This is a reproduction of a library book that was digitized by Google as part of an ongoing effort to preserve the information in books and make it universally accessible.

Google™ books

https://books.google.com

WIDENER
HN JMB7 D

Digitized by Google

2235.25.10

Harvard College Library

GIFT OF THE

BRITISH AND FOREIGN
BIBLE SOCIETY

LONDON

Digitized by Google

Digitized by Google

Digitized by Google

Bible. Yoruba. 1901)

# BIBELI MIMỌ

TABI

# MAJẸMU LAILAI ATI TITUN

London:

BRITISH AND FOREIGN BIBLE SOCIETY.

1900

Digitized by Google

2235.25.10

Harvard College Library
Sept. 23, 1910
Gift of the
British & Foreign Bible Society

HOLY BIBLE IN YORUBA

5000 *reprinted* 1908.

Digitized by Google

# ORUKỌ AWỌN IWE TI MAJẸMU LAILAI.

| | ORI |
|---|---|
| Genesisi | 50 |
| Eksodu | 40 |
| Lefitiku | 27 |
| Numeri | 36 |
| Deuteronomi | 34 |
| Joṣua | 24 |
| Awọn Onidajọ | 21 |
| Rutu | 4 |
| I. Samueli | 31 |
| II. Samueli | 24 |
| I. Awọn Ọba | 22 |
| II. Awọn Ọba | 25 |
| I. Kronika | 29 |
| II. Kronika | 36 |
| Esra | 10 |
| Nehemiah | 13 |
| Esteri | 10 |
| Jobu | 42 |
| Orin Dafidi | 150 |
| Owe | 31 |

| | ORI |
|---|---|
| Oniwasu | 12 |
| Orin Solomoni | 8 |
| Isaiah | 66 |
| Jeremiah | 52 |
| Ẹkun Jeremiah | 5 |
| Esekieli | 48 |
| Danieli | 12 |
| Hosea | 14 |
| Joeli | 3 |
| Amosi | 9 |
| Obadiah | 1 |
| Jona | 4 |
| Mika | 7 |
| Nahumu | 3 |
| Habakkuku | 3 |
| Sefania | 3 |
| Haggai | 2 |
| Sakaria | 14 |
| Malaki | 4 |

---

# ORUKỌ AWỌN IWE TI MAJẸMU TITUN.

| | ORI |
|---|---|
| Matteu | 28 |
| Marku | 16 |
| Luku | 24 |
| Johannu | 21 |
| Iṣe ti awọn Aposteli | 28 |
| Episteli si awọn ara Romu | 16 |
| I. ,, ,, ,, ,, Korinti | 16 |
| II. ,, ,, ,, ,, Korinti | 13 |
| ,, ,, ,, ,, Galatia | 6 |
| ,, ,, ,, ,, Efesu | 6 |
| ,, ,, ,, ,, Filippi | 4 |
| ,, ,, ,, ,, Kolosse | 4 |
| I. ,, ,, ,, ,, Tessalonika | 5 |
| II. ,, ,, ,, ,, Tessalonika | 3 |

| | ORI |
|---|---|
| I. Episteli si Timoteu | 6 |
| II. ,, ,, Timoteu | 4 |
| ,, ,, Titu | 3 |
| ,, ,, Filemoni | 1 |
| ,, ,, awọn Heberu | 13 |
| ,, ti Jakọbu | 5 |
| I. ,, ,, Peteru | 5 |
| II. ,, ,, Peteru | 3 |
| I. ,, ,, Johannu | 5 |
| II. ,, ,, Johannu | 1 |
| III. ,, ,, Johannu | 1 |
| ,, ,, Juda | 1 |
| Ifihàn ti Johannu | 22 |

Digitized by Google

Digitized by Google

# IWE KINI MOSE,

### TI A NPE NI

# GENESISI.

## ORI 1.

LI atetekọṣe Ọlọrun dá ọrun on aiye.
2 Aiye si wà ni jūju, o si ṣofo; òkun-
kun si wà loju ibú: Ẹmi Ọlọrun si nràbaba
loju omi.
3 Ọlọrun si wipe, Ki imọlẹ ki o wà:
imọlẹ si wà.
4 Ọlọrun si ri imọlẹ na, pe o dara:
Ọlọrun si pàla si agbedemeji imọlẹ on
òkunkun.
5 Ọlọrun si pè imọlẹ ni Ọsán, ati òkun-
kun ni Oru. Ati aṣalẹ ati owurọ̀ o di ọjọ́
kini.
6 Ọlọrun si wipe, Ki ofurufu ki o wà li
agbedemeji omi, ki o si yà omi kuro lara
omi.
7 Ọlọrun si ṣe ofurufu, o si yà omi ti o
wà nisalẹ ofurufu kuro lara omi ti o wà
loke ofurufu: o si ri bẹ̃.
8 Ọlọrun si pè ofurufu ni Ọrun. Ati
aṣalẹ ati owurọ̀ o di ọjọ́ keji.
9 Ọlọrun si wipe, Ki omi abẹ ọrun ki o
wọjọ pọ̀ si ibi kan, ki iyangbẹ ilẹ ki o si
hàn: o si ri bẹ̃.
10 Ọlọrun si pè iyangbẹ ilẹ ni Ilẹ; o si
pè iwọjọpọ̀ omi ni Okun: Ọlọrun si ri pe o
dara.
11 Ọlọrun si wipe, Ki ilẹ ki o hù oko,
eweko ti yio ma so eso, ati igi eleso ti yio
ma so eso ni irú tirẹ̀, ti o ni irugbin ninu
lori ilẹ: o si ri bẹ̃.
12 Ilẹ si sú koriko jade, eweko ti nso
eso ni irú tirẹ̀, ati igi ti nso eso, ti o ni
irugbin ninu ni irú tirẹ̀: Ọlọrun si ri pe o
dara.
13 Ati aṣalẹ ati owurọ̀ o di ọjọ́ kẹta.
14 Ọlọrun si wipe, Ki awọn imọlẹ ki o
wà li ofurufu ọrun, lati pàla ọsán on oru;
ki nwọn ki o si ma wà fun àmi, ati fun
akoko, ati fun ọjọ́, ati fun ọdún:
15 Ki nwọn ki o si jẹ́ imọlẹ li ofurufu
ọrun, lati mọlẹ sori ilẹ: o si ri bẹ̃.
16 Ọlọrun si dá imọlẹ nla meji; imọlẹ
ti o tobi lati ṣe akoso ọsán, ati imọlẹ ti o
kere lati ṣe akoso oru: o si dá awọn irawọ
pẹlu.
17 Ọlọrun si sọ wọn lọjọ̀ li ofurufu ọrun,
lati ma tàn imọlẹ sori ilẹ,
18 Ati lati ṣe akoso ọsán ati akoso oru,
ati lati pàla imọlẹ on òkunkun: Ọlọrun si
ri pe o dara.
19 Ati aṣalẹ ati owurọ̀ o di ọjọ́ kẹrin.
20 Ọlọrun si wipe, Ki omi ki o kún fun
ọ̀pọlọpọ ẹdá alãye ti nrakò, ati ki ẹiyẹ ki o
ma fò loke ilẹ li oju-ofurufu ọrun.
21 Ọlọrun si dá erinmi nlanla ati ẹdá
alãye gbogbo ti nrakò, ti omi kún fun li
ọ̀pọlọpọ ni irú wọn, ati ẹiyẹ abiyẹ ni irú rẹ̀:
Ọlọrun si ri pe o dara.
22 Ọlọrun si sure fun wọn pe, Ẹ ma bi
si i, ẹ si ma rẹ̀, ki ẹ kún inu omi li okun, ki
ẹiyẹ ki o si ma rẹ̀ ni ilẹ.
23 Ati aṣalẹ ati owurọ̀ o di ọjọ́ karun.
24 Ọlọrun si wipe, Ki ilẹ ki o mu ẹdá
alãye ni irú rẹ̀ jade wá, ẹran-ọ̀sin, ati ohun
ti nrakò, ati ẹranko ilẹ ni irú rẹ̀: o si
ri bẹ̃.
25 Ọlọrun si dá ẹranko ilẹ ni irú tirẹ̀, ati
ẹran-ọ̀sin ni irú tirẹ̀, ati ohun gbogbo ti
nrakò lori ilẹ ni irú tirẹ̀: Ọlọrun si ri pe o
dara.
26 Ọlọrun si wipe, Jẹ ki a dá enia li
aworan wa, gẹgẹ bi irí wa. ki nwọn ki o
si jọba lori ẹja okun, ati lori ẹiyẹ oju-ọrun,
ati lori ẹranko, ati lori gbogbo ilẹ, ati lori
ohun gbogbo ti nrakò lori ilẹ.
27 Bẹ̃li Ọlọrun dá enia li aworan rẹ̀, li

Digitized by Google

aworan Ọlọrun li o dá a ; ati akọ ati abo li
o dá wọn.
28 Ọlọrun si súre fun wọn. Ọlọrun si
wi fun wọn pe, Ẹ ma bi si i, ki ẹ si ma rẹ̀,
ki ẹ si gbilẹ, ki ẹ si ṣe ikawọ rẹ̀ ; ki ẹ si ma
jọba lori ẹja okun, ati lori ẹiyẹ oju-ọrun, ati
lori ohun alãye gbogbo ti nrakò lori ilẹ.
29 Ọlọrun si wipe, kiye si i, Mo fi eweko
gbogbo ti o wà lori ilẹ gbogbo ti nso eso fun
nyin, ati igi gbogbo ninu eyiti iṣe igi eleso
ti nso ; ẹnyin ni yio ma ṣe onjẹ fun.
30 Ati fun gbogbo ẹranko ilẹ, ati fun
gbogbo ẹiyẹ oju-ọrun, ati fun ohun gbogbo
ti o nrakò lori ilẹ, ti iṣe alaye, ni mo fi
eweko tutu gbogbo fun li onjẹ : o si ri bẹ̃.
31 Ọlọrun si ri ohun gbogbo ti o dá, si
kiyesi i, daradara ni. Ati aṣalẹ ati owurọ̀
o di ọjọ́ kẹfa.

## ORI 2.

BẸ li a pari ọrun on aiye, ati gbogbo
ogun wọn.
2 Ni ijọ́ keje Ọlọrun si pari iṣẹ rẹ̀ ti o ti
nṣe ; o si simi ni ijọ́ keje kuro ninu iṣẹ rẹ̀
gbogbo ti o ti nṣe.
3 Ọlọrun si busi ijọ́ keje, o si yà a si
mimọ́ ; nitori pe, ninu rẹ̀ li o simi kuro
ninu iṣẹ rẹ̀ gbogbo ti o ti bẹ̀rẹ si iṣe.
4 Itan ọrun on aiye ni wọnyi nigbati a
dá wọn li ọjọ́ ti OLUWA Ọlọrun dá aiye on
ọrun.
5 Ati olukuluku igi igbẹ ki o to wà ni
ilẹ, ati olukuluku eweko igbẹ ki nwọn ki o
to hù: OLUWA Ọlọrun kò sa ti rọ̀jo si ilẹ,
kò si sí enia kan lati ro ilẹ.
6. Ṣugbọn ikũku a ti ilẹ wá, a si ma rin
oju ilẹ gbogbo.
7 OLUWA Ọlọrun si fi erupẹ ilẹ mọ enia;
o si mí ẹmí ìye si ihò imu rẹ̀ ; enia si di
alãye ọkàn.
8 OLUWA Ọlọrun si gbìn ọgbà kan niha
ìla-õrùn ni Edeni; nibẹ̀ li o si fi ọkọnrin na
ti o ti mọ si.
9 Lati inu ilẹ li OLUWA Ọlọrun mu oni-
rũru igi hù jade wá, ti o dara ni wiwò, ti o
si dara fun onjẹ; igi ìye pẹlu lãrin ọgbà
na, ati igi ìmọ rere ati buburu.
10 Odò kan si ti Edeni ṣàn wá lati rin
ọgbà na; lati ibẹ̀ li o gbé yà, o si di ipa ori
mẹrin.
11 Orukọ ekini ni Piṣoni: on li eyiti o
yi gbogbo ilẹ Hafila ká, nibiti wurà wà;
12 Wurà ilẹ na si dara: nibẹ ni bedeliu-
mu (ojia) wà ati okuta oniki.
13 Orukọ odò keji si ni Gihoni: on na li
eyiti o yi gbogbo ilẹ Kuṣi ká.
14 Ati orukọ odò kẹta ni Hiddekeli: on
li eyiti nṣàn lọ si ìha ìla-õrùn Assiria. Ati
odò kẹrin ni Euferate.
15 OLUWA Ọlọrun si mu ọkọnrin na, o
si fi i sinu ọgbà Edeni lati ma ro o, ati lati
ma ṣọ́ ọ.
16 OLUWA Ọlọrun si fi aṣẹ fun ọkọnrin
na pe, Ninu gbogbo igi ọgbà ni ki iwọ ki
o ma jẹ :
17 Ṣugbọn ninu igi ìmọ rere ati bururu
nì, iwọ kò gbọdọ jẹ ninu rẹ̀: nitoripe li
ọjọ́ ti iwọ ba jẹ ninu rẹ̀ kikú ni iwọ o kú.
18 OLUWA Ọlọrun si wipe, kò dara ki
ọkọnrin na ki o nikan ma gbé ; emi o ṣe
oluranlọwọ ti o dabi rẹ̀ fun u.
19 Lati inu ilẹ li OLUWA Ọlọrun si ti dá
ẹranko igbẹ gbogbo, ati ẹiyẹ oju-ọrun gbo-
gbo ; o si mu wọn tọ̀ Adamu wá lati wò
orukọ ti yio sọ wọn ; orukọkorukọ ti Adamu
si sọ olukuluku ẹda alãye, on li orukọ rẹ̀.
20 Adamu si sọ ẹran-ọ̀sin gbogbo, ati
ẹiyẹ oju-ọrun, ati ẹranko igbẹ gbogbo, li
orukọ ; ṣugbọn fun Adamu a kò ri oluran-
lọwọ ti o dabi rẹ̀ fun u.
21 OLUWA Olọrun si mu orun ìjika kùn
Adamu o si sùn : o si yọ ọkan ninu egun-
gun-ìha rẹ̀, o si fi ẹran di ipò rẹ̀:
22 OLUWA Ọlọrun si fi egungun-ìha ti o
mu ni ìha ọkọnrin na mọ obirin, o si mu u
tọ̀ ọkọnrin na wá.
23 Adamu si wipe, Eyiyi li egungun
ninu egungun mi, ati ẹran-ara ninu ẹran-
ara mi : Obirin li a o ma pè e, nitori ti a
mu u jade lati ara ọkọnrin wá.
24 Nitori na li ọkọnrin yio ṣe ma fi baba
on iya rẹ̀ silẹ, yio si fi ara mọ́ aya rẹ̀ : nwọn
o si di ara kan.
25 Awọn mejeji si wà ni ìhoho, ati
ọkọnrin na ati obirin rẹ̀, nwọn kò si tiju.

## ORI 3.

EJO sa ṣe arakereke jù ẹranko igbẹ iyoku
lọ ti OLUWA Ọlọrun ti dá. O si wi
fun obirin na pe, õtọ li Ọlọrun wipe, Ẹnyin
kò gbọdọ jẹ gbogbo eso igi ọgbà ?
2 Obirin na si wi fun ejò na pe, Awa a
ma jẹ ninu eso igi ọgbà :
3 Ṣugbọn ninu eso igi nì ti o wà lãrin
ọgbà Ọlọrun ti wipe, Ẹnyin kò gbọdọ jẹ
ninu rẹ̀, bẹ̃li ẹnyin kò gbọdọ fọwọkàn a, ki
ẹnyin ki o má ba kú.
4 Ejò na si wi fun obirin na pe, Ẹnyin
ki yio ku ikú kikú kan.
5 Nitori Ọlọrun mọ̀ pe, li ọjọ́ ti ẹnyin
ba jẹ ninu rẹ̀, nigbana li oju nyin o là,

Digitized by Google

ẹnyin o si dabi Ọlọrun, ẹ o mọ̀ rere ati buburu.

6 Nigbati obirin na si ri pe, igi na dara ni jijẹ, ati pe, o si dara fun oju, ati igi ti a ifẹ lati mu ni gbọ́n, o mu ninu eso rẹ̀ o si jẹ, o si fi fun ọkọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀, on si jẹ.

7 Oju awọn mejeji si là, nwọn si mọ̀ pe nwọn wà ni ìhoho; nwọn sí gán ewe ọpọtọ pọ̀, nwọn si dá ibantẹ fun ara wọn.

8 Nwọn si gbọ́ ohùn OLUWA Ọlọrun, o nrìn ninu ọgbà ni itura ọjọ́: Adamu ati aya rẹ̀ si fi ara wọn pamọ́ kuro niwaju OLUWA Ọlọrun lãrin igi ọgbà.

9 OLUWA Ọlọrun si kọ si Adamu, o si wi fun u pe, Nibo ni iwọ wà?

10 O si wipe, Mo gbọ́ ohùn rẹ ninu ọgbà, ẹ̀ru si bà mi, nitori ti mo wà ni ìhoho; mo si fi ara pamọ́.

11 O si wi pe, Tali o wi fun ọ pe iwọ wà ni ìhoho? iwọ ha jẹ ninu igi ni, ninu eyiti mo paṣẹ fun ọ pe iwọ kò gbọdọ jẹ?

12 Ọkọnrin na si wipe, Obirin ti iwọ fi pẹlu mi, on li o fun mi ninu eso igi na, emi si jẹ.

13 OLUWA Ọlọrun si bi obirin na pe, Ewo ni iwọ ṣe yi? Obirin na si wipe, Ejò li o tàn mi, mo si jẹ.

14 OLUWA Ọlọrun si wi fun ejò na pe, nitori ti iwọ ti ṣe eyi, a fi iwọ bú ninu gbogbo ẹran ati ninu gbogbo ẹranko igbẹ; inu rẹ ni iwọ o ma fi wọ́, erupẹ ilẹ ni iwọ o ma jẹ li ọjọ́ aiye rẹ gbogbo.

15 Emi o si fi ọta sãrin iwọ ati obirin na, ati sãrin irú-ọmọ rẹ ati irú-ọmọ rẹ̀: on o fọ́ ọ li ori, iwọ o si pa a ni gigìsẹ.

16 Fun obirin na li o wipe, Emi o sọ ipọnju ati iloyun rẹ di pupọ̀; ni ipọnju ni iwọ o ma bimọ; lọdọ ọkọ rẹ ni ifẹ rẹ yio ma fà si, on ni yio si ma ṣe olori rẹ.

17 O si wi fun Adamu pe, Nitoriti iwọ gbà ohùn aya rẹ gbọ́, ti iwọ si jẹ ninu eso igi na, ninu eyiti mo ti paṣẹ fun ọ pe, iwọ kò gbọdọ jẹ ninu rẹ̀; a fi ilẹ bú nitori rẹ; ni ipọnju ni iwọ o ma jẹ ninu rẹ̀ li ọjọ́ aiye rẹ gbogbo;

18 Ẹgún on oṣuṣu ni yio ma hù jade fun ọ, iwọ o si ma jẹ eweko igbẹ:

19 Li õgùn oju rẹ ni iwọ o ma jẹun, titi iwọ o fi pada si ilẹ; nitori inu rẹ̀ li a ti mu ọ wá, erupẹ sa ni iwọ, iwọ o si pada di erupẹ.

20 Adamu si pè orukọ aya rẹ̀ ni Efa; nitori on ni iṣe iya alãye gbogbo.

21 Ati fun Adamu ati fun aya rẹ̀ li OLUWA Ọlọrun da ẹwu awọ, o si fi wọ̀ wọn.

22 OLUWA Ọlọrun si wipe, Wò o, Ọkọnrin na dabi ọkan ninu wa lati mọ̀ rere ati buburu: njẹ nisisiyi ki o má ba nà ọwọ́ rẹ̀ ki o si mu ninu eso igi ìye pẹlu, ki o si jẹ, ki o si yè titi lai;

23 Nitorina OLUWA Ọlọrun lé e jade kuro ninu ọgbà Edeni, lati ma ro ilẹ ninu eyiti a ti mu u jade wá.

24 Bẹ̃li o lé ọkọnrin na jade; o si fi awọn kerubu ati idà ina dè ìha ìla-õrùn Edeni ti njù kakiri, lati ma ṣọ́ ọ̀na igi ìye na.

## ORI 4.

ADAMU si mọ̀ Efa aya rẹ̀; o si loyun, o si bí Kaini, o si wipe, Mo ri ọkọnrin kan gbà lọwọ OLUWA.

2 O si bí Abeli arakọnrin rẹ̀. Abeli a si ma ṣe oluṣọ-agutan, ṣugbọn Kaini a ma ṣe alaroko.

3 O si ṣe, li opin ọjọ́ wọnni ti Kaini mu ọrẹ ninu eso ilẹ fun OLUWA wá.

4 Ati Abeli, on pẹlu mu ninu akọbi ẹran-ọ̀sin ani ninu awọn ti o sanra. OLUWA si fi ojurere wò Abeli ati ọrẹ rẹ̀;

5 Ṣugbọn Kaini ati ọrẹ rẹ̀ ni kò nãni. Kaini si binu gidigidi, oju rẹ̀ si rẹ̀wẹsi.

6 OLUWA si bi Kaini pe, Ẽṣe ti inu fi mbi ọ? ẽ si ti ṣe ti oju rẹ̀ fi rẹ̀wẹsi?

7 Bi iwọ ba ṣe rere, ara ki yio ha yá ọ? bi iwọ kò ba si ṣe rere, ẹ̀ṣẹ ba li ẹnu-ọ̀na, lọdọ rẹ ni ifẹ rẹ̀ yio ma fà si, iwọ o si ma ṣe alakoso rẹ̀.

8 Kaini si ba Abeli arakọnrin rẹ̀ sọrọ: o si ṣe, nigbati nwọn wà li oko, Kaini dide si Abeli arakọnrin rẹ̀, o si lù u pa.

9 OLUWA si wi fun Kaini pe, Nibo ni Abeli arakọnrin rẹ wà? O si wipe, Emi kò mọ̀; emi iṣe olutọju arakọnrin mi bi?

10 O si wipe, Kini iwọ ṣe nì? Ohùn ẹ̀jẹ arakọnrin rẹ nkigbe pè mi lati inu ilẹ wá.

11 Njẹ nisisiyi a fi ọ ré lori ilẹ, ti o yanu rẹ̀ gbà ẹ̀jẹ arakọnrin rẹ lọwọ rẹ.

12 Nigbati iwọ ba ro ilẹ, lati isisiyi lọ, ki yio fi agbara rẹ̀ so eso fun ọ mọ; isansa ati alarinkiri ni iwọ o ma jẹ li aiye.

13 Kaini si wi fun OLUWA pe, ìya ẹ̀ṣẹ mi pọ̀ jù eyiti emi lè rù lọ.

14 Kiye si i, iwọ lé mi jade loni kuro lori ilẹ; emi o si di ẹniti o pamọ kuro loju rẹ; emi o si ma jẹ isana ati alarinkiri li aiye; yio si ṣe ẹnikẹni ti o ba ri mi yio lù mi pa.

15 OLUWA si wi fun u pe, Nitorina ẹnikẹni ti o ba pa Kaini, a o gbẹsan lara rẹ̀ lẹrinmeje. OLUWA si sàmi si Kaini lara, nitori ẹniti o ba ri i ki o má ba pa a.

Digitized by Google

16 Kaini si jade lọ kuro niwaju OLUWA,
o si joko ni ilẹ Nodi, niha ìla-õrùn Edeni.
17 Kaini si mọ̀ aya rẹ̀; o si loyun, o si
bí Enoku: o si tẹ̀ ilu kan dó, o si sọ orukọ
ilu na ni Enoku bi orukọ ọmọ rẹ̀ ọkọnrin.
18 Fun Enoku li a bí Iradi: Iradi si bí
Mehujaeli: Mehujaeli si bí Metuṣaeli:
Metuṣaeli si bí Lameki.
19 Lameki si fẹ̀ obirin meji: orukọ ekini
ni Ada, ati orukọ ekeji ni Silla.
20 Ada si bí Jabali: on ni baba irú
awọn ti o ngbé agọ́, ti nwọn si li ẹran-ọ̀sin.
21 Orukọ arakọnrin rẹ̀ ni Jubali: on ni
baba irú gbogbo awọn ti nlò dùru ati fère.
22 Ati Silla, on pẹlu bí Tubali-kaini,
olukọni gbogbo ọlọnà idẹ, ati irin: ara-
birin Tubali-kaini ni Naama.
23 Lameki si wi fun awọn aya rẹ̀ pe,
Ada on Silla, ẹ gbọ́ ohùn mi; ẹnyin aya
Lameki, ẹ fetisi ọ̀rọ mi: nitoriti mo pa
ọkọnrin kan si ẹ̀dun mi, ati ọdọmọkọnrin
kan si ipalara mi.
24 Bi a o gbẹsan Kaini lẹrinmeje, njẹ ti
Lameki ni ìgba ãdọrin meje.
25 Adamu si tun mọ̀ aya rẹ̀, o si bí
ọmọkọnrin kan, o si pè orukọ rẹ̀ ni Seti:
o wipe, nitori Ọlọrun yàn irú-ọmọ miran
fun mi ni ipò Abeli ti Kaini pa.
26 Ati Seti, on pẹlu li a bí ọmọkọnrin
kan fun; o si pè orukọ rẹ̀ ni Enosi: ni-
gbana li awọn enia bẹ̀rẹ si ikepè orukọ
OLUWA.

## ORI 5.

EYI ni iwe iran Adamu: Li ọjọ́ ti Ọlọrun
dá ọkọnrin, li aworan Ọlọrun li o
dá a.
2 Ati akọ ati abo li o dá wọn; o si súre
fun wọn, o si pè orukọ wọn ni Adamu li
ọjọ́ ti a dá wọn.
3 Adamu si wà li ãdoje ọdún, o si bí
ọmọkọnrin kan ni jijọ ati li aworan ara rẹ̀;
o si pè orukọ rẹ̀ ni Seti:
4 Ọjọ́ Adamu, lẹhin ti o bí Seti, jẹ ẹgbẹ-
rin ọdún: o si bí ọmọkọnrin ati ọmọbirin:
5 Gbogbo ọjọ́ ti Adamu wà si jẹ ẹ̃dẹgbẹ-
run ọdún o lé ọgbọ̀n: o si kú.
6 Seti si wà li ọgọrun ọdún o lé marun,
o si bí Enoṣi:
7 Seti si wà li ẹgbẹrin ọdún o lé meje
lẹhin ti o bí Enoṣi, o si bí ọmọkọnrin ati
ọmọbirin:
8 Ati gbogbo ọjọ́ Seti jẹ ẹ̃dẹgbẹrun ọdun
o lé mejila: o si kú.
9 Enoṣi si wà li ãdọrun ọdún, o si bí
Kenani:
10 Enoṣi si wà li ẹgbẹrin ọdún o lé
mẽdogun lẹhin ti o bí Kenani, o si bí ọmọ-
kọnrin ati ọmọbirin:
11 Gbogbo ọjọ́ Enoṣi si jẹ ẹ̃dẹgbẹrun
ọdún o lé marun: o si kú.
12 Kenani si wà li ãdọrin ọdún, o si bí
Mahalaleli:
13 Kenani si wà li ẹgbẹrin ọdún o lé
ogoji lẹhin ti o bí Mahalaleli, o si bí ọmọ-
kọrin ati ọmọbirin:
14 Gbogbo ọjọ́ Kenani si jẹ ẹ̃dẹgbẹrun
ọdún o lé mẹwa: o si kú.
15 Mahalaleli si wà li ọgọta ọdún o le
marun, o si bí Jaredi:
16 Mahalaleli si wà li ẹgbẹrin ọdún o lé
ọgbọ̀n lẹhin ti o bí Jaredi, o si bí ọmọkọn-
rin ati ọmọbirin:
17 Gbogbo ọjọ́ Mahalaleli si jẹ ẹ̃dẹgbẹ̀run
ọdún o dí marun: o si kú.
18 Jaredi si wà li ọgọjọ ọdún o lé meji,
o si bí Enoku:
19 Jaredi si wà li ẹgbẹrin ọdún lẹhin
igbati o bi Enoku, o si bí ọmọkọnrin ati
ọmọbirin:
20 Gbogbo ọjọ́ Jaredi si jẹ ẹgbẹrun ọdún
o dí mejidilogoji: o si kú.
21 Enoku si wà li ọgọta ọdún o lé marun,
o si bí Metusela:
22 Enoku si ba Ọlọrun rìn li ọ̃dunrun
ọdún lẹhin ti o bi Metusela, o si bí ọmọ-
kọnrin ati ọmọbirin:
23 Gbogbo ọjọ́ Enoku si jẹ irinwo ọdún
o dí marundilogoji:
24 Enoku si ba Ọlọrun rìn: on kò si sí;
nitoriti Ọlọrun mu u lọ.
25 Metusela si wà li ọgọsan ọdún o lé
meje, o si bí Lameki:
26 Metusela si wà li ẹgbẹrin ọdún o dí
mejidilogun lẹhin igbati o bí Lameki, o si
bí ọmọkọnrin ati ọmọbirin:
27 Gbogbo ọjọ́ Metusela si jẹ ẹgbẹrun
ọdún o dí mọkanlelọgbọ̀n: o si kú.
28 Lameki si wà li ọgọsan ọdún o lé me-
ji, o si bí ọmọkọnrin kan:
29 O si sọ orukọ rẹ̀ ni Noa, pe, Eleyi ni
yio tù wa ni inu ni iṣẹ ati lãla ọwọ́ wa, ni-
tori ilẹ ti OLUWA ti fibú.
30 Lameki si wà li ẹgbẹta ọdún o dí ma-
run, lẹhin ti o bí Noa, o si bí ọmọkọnrin
ati ọmọbirin:
31 Gbogbo ọjọ́ Lameki si jẹ ẹgbẹrin ọdún
o dí mẹtalelogun: o si kú.
32 Noa si jẹ ẹni ẹ̃dẹgbẹta ọdún: Noa si
bí Ṣemu, Hamu, ati Jafeti.

Digitized by Google

## ORI 6.

O SI ṣe nigbati enia bẹ̀rẹ si irẹ̀ lori ilẹ, ti
a si bí ọmọbirin fun wọn,
2 Ni awọn ọmọ Ọlọrun ri awọn ọmọbirin
enia pe, nwọn lẹwà; nwọn fẹ́ aya fun ara
wọn ninu gbogbo awọn ti nwọn yàn.
3 OLUWA si wipe, Ẹmi mi ki yio fi igba-
gbogbo ba enia jà, ẹran-ara sa li on pẹlu:
ọjọ́ rẹ̀ yio si jẹ ọgọfa ọdún.
4 Awọn òmirán wà li aiye li ọjọ́ wọnni;
ati lẹhin eyini pẹlu, nigbati awọn ọmọ Ọlọ-
run wọle tọ̀ awọn ọmọbirin enia lọ, ti nwọn
si bí ọmọ fun wọn, awọn na li o di akọni ti
o wà nigbãni, awọn ọkọnrin olokikí.
5 Ọlọrun si ri pe ìwabuburu enia di pipọ̀
li aiye, ati pe gbogbo ìro ọkàn rẹ̀ kìki ibi
ni lojojumọ.
6 Inu OLUWA si bajẹ nitori ti o dá enia
si aiye, o si dùn u de ọkàn rẹ̀.
7 OLUWA si wipe, Emi o pa enia ti mo ti
dá run kuro li ori ilẹ; ati enia, ati ẹranko,
ati ohun ti nrakò, ati ẹiyẹ oju-ọrun; nitori
inu mi bajẹ ti mo ti dá wọn.
8 Ṣugbọn Noa ri ojurere loju OLUWA.
9 Wọnyi ni ìtan Noa: Noa ṣe olõtọ ati
ẹniti o pé li ọjọ́ aiye rẹ̀, Noa mba Ọlọrun
rìn.
10 Noa si bí ọmọkọnrin mẹta, Ṣemu,
Hamu, ati Jafeti.
11 Aiye si bajẹ niwaju Ọlọrun, aiye si
kún fun ìwa-agbara.
12 Ọlọrun si bojuwò aiye, si kiye si i, o
bajẹ; nitori olukuluku enia ti bà ìwa rẹ̀ jẹ
li aiye.
13 Ọlọrun si wi fun Noa pe, Opin gbogbo
enia de iwaju mi; nitori ti aiye kún fun
ìwa-agbara lati ọwọ́ wọn; si kiye si i, emi
o si pa wọn run pẹlu aiye.
14 Iwọ fi igi goferi kàn ọkọ̀ kan; ikele-
ikele ni iwọ o ṣe ninu ọkọ̀ na, iwọ o si fi
ọ̀da kùn u ninu ati lode.
15 Bayi ni iwọ o si ṣe e: Ìna ọkọ̀ na yio
jẹ ọ̃dunrun igbọ́nwọ, ìbo rẹ̀ ãdọta igbọ́nwọ,
ati giga rẹ̀ ọgbọ̀n igbọ̀nwọ.
16 Ferese ni iwọ o si ṣe si ọkọ̀ na, ni
igbọ́nwọ kan ni ki iwọ ki o si pari wọn
loke; lẹgbẹ ni iwọ o si dá ẹnu-ọ̀na ọkọ̀ na
si: pẹlu yara isalẹ atẹle, ati ẹkẹta loke ni
iwọ o ṣe e.
17 Ati emi, wò o, emi nmu kikun-omi
bọ̀ wá si aiye, lati pa gbogbo ohun alãye
run, ti o li ẹmi ãye ninu, kuro labẹ ọrun;
ohun gbogbo ti o wà li aiye ni yio si kú.
18 Ṣugbọn iwọ li emi o ba dá majẹmu
mi; iwọ o si wọ̀ inu ọkọ̀ na, iwọ, ati awọn
ọmọ rẹ, ati aya rẹ, ati awọn aya awọn ọmọ
rẹ pẹlu rẹ.
19 Ati ninu ẹdá alãye gbogbo, ninu oni-
rũru ẹran, meji meji ninu gbogbo ẹran ni
iwọ o mu wọ̀ inu ọkọ̀ na, lati mu nwọn là
pẹlu rẹ; ti akọ ti abo ni ki nwọn ki o jẹ.
20 Ninu ẹiyẹ nipa irú ti wọn, ninu ẹran-
ọ̀sin nipa irú ti wọn, ninu ohun gbogbo ti
nrakò ni ilẹ nipa irú tirẹ̀ meji meji ninu
gbogbo wọn ni yio ma tọ̀ ọ wá, lati mu wọn
wà lãye.
21 Iwọ o si mu ninu ohun jijẹ gbogbo,
iwọ o si kó wọn jọ si ọdọ rẹ; yio si ṣe onjẹ
fun iwọ, ati fun wọn.
22 Bẽni Noa si ṣe; gẹgẹ bi gbogbo eyiti
Ọlọrun paṣẹ fun u, bẹli o ṣe.

## ORI 7.

OLUWA si wi fun Noa pe, iwọ wá, ati
gbogbo awọn ara ile rẹ sinu ọkọ̀, ni-
tori iwọ ni mo ri li olododo niwaju mi ni
iran yi.
2 Ninu onirũru ẹran ti o mọ́ meje meje
ni ki iwọ ki o mu wọn, ati akọ ati abo rẹ̀;
ati ninu ẹran ti kò mọ́ meji meji, ati akọ
ati abo rẹ̀.
3 Ninu ẹiyẹ oju-orun pẹlu ni meje meje,
ati akọ ati abo; lati dá irú si lãye lori ilẹ
gbogbo.
4 Nitori ijọ́ meje si i, emi o mu òjo rọ̀ si
ilẹ li ogoji ọsán ati li ogoji oru; ohun alãye
gbogbo ti mo dá li emi o parun kuro lori
ilẹ.
5 Noa si ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti OLUWA
paṣẹ fun u.
6 Noa si jẹ ẹni ẹgbẹta ọdún nigbati kí-
kun-omi de si aiye.
7 Noa si wọle, ati awọn ọmọ rẹ̀, ati aya
rẹ̀, ati aya awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀, sinu ọkọ̀,
nitori kíkun-omi.
8 Ninu ẹranko mimọ́, ati ninu ẹranko ti
kò mọ́, ati ninu ẹiyẹ, ati ninu ohun gbogbo
ti nrakò lori ilẹ.
9 Nwọn wọle tọ̀ Noa lọ sinu ọkọ̀ ni meji
meji, ati akọ ati abo, bi Ọlọrun ti fi aṣẹ fun
Noa.
10 O si ṣe ni ijọ́ keje, bẽni kíkun-omi
de si aiye.
11 Li ẹgbẹta ọdún ọjọ́ aiye Noa, li oṣù
keji, ni ọjọ́ kẹtalelogun oṣù, li ọjọ́ na ni
gbogbo isun ibú nla ya, ati ferese iṣàn omi
ọrun si ṣí silẹ.
12 Ojo na si wà lori ilẹ li ogoji ọsán on
ogoji oru.
13 Li ọjọ́ na gan ni Noa wọ̀ inu ọkọ̀, ati
Ṣemu, ati Hamu, ati Jafeti, awọn ọmọ Noa,



Digitized by Google

ati aya Noa, (ati awọn aya ọmọ rẹ̀ mẹta
pẹlu wọn).
14 Awọn, ati gbogbo ẹranko ni irú tirẹ̀,
ati ẹran-ọ̀sin gbogbo ni irú tirẹ̀, ati ohun
gbogbo ti nrakò lori ilẹ ni irú tirẹ̀ ati gbogbo
ẹiyẹ nla ni irú tirẹ̀, ati gbogbo ẹiyẹ abiyẹ.
15 Nwọn si wọle tọ̀ Noa lọ sinu ọkọ̀,
meji meji ninu ẹda gbogbo, ninu eyiti ẹmi
ìye wà.
16 Awọn ti o si wọle lọ, nwọn wọle ti
akọ ti abo ninu ẹdá gbogbo, bi Ọlọrun ti fi
aṣẹ fun u. OLUWA si sé e mọ́ ile.
17 Ikún-omi si wà li ogoji ọjọ́ lori ilẹ;
omi si nwú si i, o si mu ọkọ̀ fó soke, o si
gbera kuro lori ilẹ.
18 Omi si gbilẹ, o si nwú si i gidigidi
lori ilẹ; ọkọ̀ na si fó soke loju omi.
19 Omi si gbilẹ gidigidi lori ilẹ; ati
gbogbo oke giga, ti o wà ni gbogbo abẹ
ọrun, li a bò mọlẹ.
20 Omi gbilẹ soke ni igbọ́nwọ mẽdogun;
a si bò gbogbo okenla mọlẹ.
21 Gbogbo ẹdá ti nrìn lori ilẹ si kú, ti
ẹiyẹ, ti ẹran-ọ̀sin, ti ẹranko, ti ohun gbogbo
ti nrakò lori ilẹ, ati gbogbo enia:
22 Gbogbo ohun ti ẹmi ìye wà ni ihò
imu rẹ̀, gbogbo ohun ti o wà ni iyangbẹ ilẹ
si kú.
23 Ohun alãye gbogbo ti o wà lori ilẹ li
a si parun, ati enia, ati ẹran-ọ̀sin, ati ohun
ti nrakò, ati ẹiyẹ oju-ọrun, nwọn si run
kuro lori ilẹ. Noa nikan li o kù, ati awọn
ti o wà pẹlu rẹ̀ ninu ọkọ̀.
24 Omi si gbilẹ li aiye li ãdọjọ ọjọ́.

## ORI 8.

OLỌRUN si ranti Noa, ati ohun alãye
gbogbo, ati gbogbo ẹran-ọ̀sin ti o wà
pẹlu rẹ̀ ninu ọkọ̀: Ọlọrun si mu afẹfẹ kọja
lori ilẹ, omi na si fà.
2 A si dí gbogbo isun ibú ati awọn ferese
ọrun, o si mu òjo dá lati ọrun wá.
3 Omi si npada kuro lori ilẹ lojojumọ
lẹhin ãdọjọ ọjọ́, omi si fà.
4 Ọkọ̀ si kanlẹ li oṣù keje, ni ijọ́ kẹtadi-
logun oṣù, lori oke Ararati.
5 Omi si nfà titi o fi di oṣù kẹwa: li
oṣù kẹwa, li ọjọ́ kini oṣù li ori awọn okenla
hàn.
6 O si ṣe li opin ogoji ọjọ́, ni Noa ṣí
ferese ọkọ̀ ti o kàn:
7 O si rán ìwo kan jade, ti o fò jade lọ
ka kiri titi omi fi gbẹ kuro lori ilẹ.
8 O si rán oriri kan jade, lati ọdọ rẹ̀ lọ,
ki o wò bi omi ba nfà kuro lori ilẹ;
9 Ṣugbọn oriri kò ri ibi isimi fun atẹlẹsẹ̀
rẹ̀, o si pada tọ̀ ọ lọ ninu ọkọ̀, nitoriti omi
wà lori ilẹ gbogbo: nigbana li o si nawọ
rẹ̀, o mu u, o si fà a si ọdọ rẹ̀ ninu ọkọ̀.
10 O si duro li ọjọ́ meje miran si i: o si
tun rán oriri na jade lati inu ọkọ̀ lọ.
11 Oriri na si pada wọle tọ̀ ọ wá li
aṣalẹ; si kiye si i, o já ewe olifi si ẹnu rẹ̀:
bẽli Noa si mọ̀ pe omi ngbẹ kuro lori ilẹ.
12 O si tun duro ni ijọ́ meje miran, o si
rán oriri na jade; ti kò si tun pada tọ̀ ọ
wá mọ́.
13 O si ṣe li ọdún kọkanlelẹgbẹta, li oṣù
kini, li ọjọ́ kini oṣù na, on li omi gbẹ kuro
lori ilẹ: Noa si ṣí ideri ọkọ̀, o si wò, si
kiye si i ori ilẹ gbẹ.
14 Li oṣù keji, ni ijọ́ kẹtadilọgbọ̀n oṣù,
on ni ilẹ gbẹ.
15 Ọlọrun si sọ fun Noa pe,
16 Jade kuro ninu ọkọ̀, iwọ, ati aya rẹ,
ati awọn ọmọ rẹ, ati awọn aya ọmọ rẹ pẹlu
rẹ.
17 Mu ohun alãye gbogbo ti o wà pẹlu
rẹ jade pẹlu rẹ, ninu ẹdá gbogbo, ti ẹiyẹ,
ti ẹran-ọ̀sin, ati ti ohun gbogbo ti nrakò
lori ilẹ; ki nwọn ki o le ma gbá yìn lori
ilẹ, ki nwọn bí si i, ki nwọn si ma rẹ̀ si i
lori ilẹ.
18 Noa si jade, ati awọn ọmọ rẹ̀, ati aya
rẹ̀, ati awọn aya ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀;
19 Gbogbo ẹranko, gbogbo ohun ti nrakò,
ati ẹiyẹ gbogbo, ati ohunkohun ti nrakò
lori ilẹ, gẹgẹ bi irú ti wọn, nwọn jade ninu
ọkọ̀.
20 Noa si tẹ́ pẹpẹ fun OLUWA; o si mu
ninu ẹranko mimọ́ gbogbo, ati ninu ẹiyẹ
mimọ́ gbogbo, o si rú ẹbọ-ọrẹ sisun lori
pẹpẹ na.
21 OLUWA si gbọ́ õrun didùn; OLUWA
si wi li ọkàn rẹ̀ pe, Emi ki yio si tun fi ilẹ
ré nitori enia mọ́; nitori ìro ọkàn enia ibi
ni lati ìgba ewe rẹ̀ wá; bẽli emi ki yio tun
kọlù ohun alãye gbogbo mọ́ bi mo ti ṣe.
22 Niwọ̀n ìgba ti aiye yio wà, ìgba iru-
gbìn, ati ìgba ikore, ìgba otutu ati oru, ìgba
ẹ̀rùn on òjo, ati ọsán ati oru, ki yio dẹkun.

## ORI 9.

OLỌRUN si sure fun Noa, ati fun awọn
ọmọ rẹ̀, o si wi fun wọn pe, Ẹ ma bí
si i, ẹ si ma rẹ̀, ki ẹ si kún aiye.
2 Ati ìbẹru nyin, ati ìfoya nyin, yio ma
wà lara gbogbo ẹranko aiye, ati lara gbogbo
ẹiyẹ oju-ọrun, ati lara gbogbo ohun ti
nrakò ni ilẹ, ati lara gbogbo ẹja okun;
ọwọ́ nyin li a fi wọn lé.
3 Gbogbo ohun alãye, ti nrakò, ni yio

Digitized by Google

ma ṣe onjẹ fun nyin; gẹgẹ bi eweko tutu
ni mo fi ohun gbogbo fun nyin.
4 Kìki ẹran pẹlu ẹmi rẹ̀, ani ẹ̀jẹ̀ rẹ̀, on
li ẹnyin kò gbọdọ jẹ.
5 Nitõtọ ẹ̀jẹ nyin ani ẹmi nyin li emi o
si bère; lọwọ gbogbo ẹranko li emi o bère
rẹ̀, ati lọwọ enia, lọwọ arakọnrin olukuluku
enia li emi o bère ẹmi enia.
6 Ẹnikẹni ti o ba ta ẹ̀jẹ enia silẹ, lati
ọwọ́ enia li a o si ta ẹ̀jẹ rẹ̀ silẹ: nitoripe li
aworan Ọlọrun li o dá enia.
7 Ati ẹnyin, ki ẹnyin ki o ma bí si i;
ki ẹ si ma rẹ̀ si i, ki ẹ si ma gbá yìn lori
ilẹ, ki ẹ si ma rẹ̀ ninu rẹ̀.
8 Ọlọrun si wi fun Noa, ati fun awọn
ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀, pe,
9 Ati emi, kiye si i, emi ba nyin dá
majẹmu mi, ati awọn irú-ọmọ nyin lẹhin
nyin;
10 Ati gbogbo ẹdá alãye ti o wà pẹlu
nyin; ti ẹiyẹ, ti ẹran-ọ̀sin, ati ẹranko aiye
pẹlu nyin; lati gbogbo awọn ti o ti inu
ọkọ̀ jade, titi o fi de gbogbo ẹranko aiye.
11 Emi o si ba nyin dá majẹmu mi;
a ki yio si fi kíkun-omi ké gbogbo ẹdá kuro
mọ́; bẽni kíkun-omi ki yio sí mọ́, lati pa
aiye run.
12 Ọlọrun si wipe, Eyiyi li àmi majẹmu
mi ti mo ba nyin dá, ati gbogbo ẹdá alãye
ti o wà pẹlu nyin, fun atirandiran:
13 Mo fi ọ̀ṣumare mi si awọsanma, on ni
yio si ma ṣe àmi majẹmu mi ti mo ba aiye
dá.
14 Yio si ṣe, nigbati mo ba mu awọsanma
wá si ori ilẹ, a o si ma ri ọ̀ṣumare na li
awọsanma:
15 Emi o si ranti majẹmu mi, ti o wà
lãrin emi ati ẹnyin, ati gbogbo ọkàn alãye
ni gbogbo ẹdá; omi ki yio si di kìkun mọ́
lati pa gbogbo ẹdá run.
16 Ọṣumare na yio si wà li awọsanma;
emi o si ma wò o, ki emi le ma ranti ma-
jẹmu lailai ti o wà pẹlu Ọlọrun ati gbogbo
ọkàn alãye ti o wà ninu gbogbo ẹdá ti o
wà li aiye.
17 Ọlọrun si wi fun Noa pe, Eyiyi li
àmi majẹmu na, ti mo ba ara mi ati ẹdá
gbogbo ti o wà lori ilẹ dá.
18 Awọn ọmọ Noa, ti o si jade ninu ọkọ̀
ni Ṣemu, ati Hamu, ati Jafeti: Hamu si
ni baba Kenaani.
19 Awọn mẹta wọnyi li ọmọ Noa: lati
ọdọ wọn li a gbé ti tànka gbogbo aiye.
20 Noa si bẹ̀rẹ si iṣe àgbẹ, o si gbìn
ọgba-àjara:
21 O si mu ninu ọti-waini na, o mu
amupara; o si tú ara rẹ̀ si ìhoho ninu
agọ́ rẹ̀.
22 Hamu, baba Kenaani, si ri ìhoho
baba rẹ̀, o si sọ fun awọn arakọnrin rẹ̀ meji
lode.
23 Ati Ṣemu ati Jafeti mu gọgọwu,
nwọn si fi le ejika awọn mejeji, nwọn si fi
ẹhìn rìn, nwọn si bò ìhoho baba wọn; oju
wọn si wà lẹhin; nwọn kò si ri ìhoho baba
wọn.
24 Noa si jí kuro li oju ọti-waini rẹ̀, o
si mọ̀ ohun ti ọmọ rẹ̀ kekere ṣe si i.
25 O si wipe, Egbe ni fun Kenaani;
iranṣẹ awọn iranṣẹ ni yio ma ṣe fun awọn
arakọnrin rẹ̀.
26 O si wipe, Olubukun li OLUWA
Ọlọrun Ṣemu; Kenaani yio ma ṣe iranṣẹ
rẹ̀.
27 Ọlọrun yio mu Jafeti gbilẹ, yio si ma
gbé agọ́ Ṣemu; Kenaani yio si ma ṣe iranṣẹ
wọn.
28 Noa si wà ni irinwo ọdun o dí ãdọta,
lẹhin kíkun-omi.
29 Gbogbo ọjọ́ Noa jẹ ẹgbẹrun ọdún o dí
ãdọta: o si kú.

## ORI 10.

IRAN awọn ọmọ Noa ni wọnyi, Ṣemu,
Hamu, ati Jafeti: ati fun wọn li a si
bí ọmọ lẹhin kíkun-omi.
2 Awọn ọmọ Jafeti; Gomeri, ati Magogu,
ati Madai, ati Jafani, ati Tubali, ati Me-
ṣeki, ati Tirasi.
3 Ati awọn ọmọ Gomeri, Aṣkenasi, ati
Rifati, ati Togarma.
4 Ati awọn ọmọ Jafani; Eliṣa, ati Tar-
ṣiṣi, Kittimu, ati Dodanimu.
5 Lati ọdọ awọn wọnyi li a ti pín ere-
kuṣu awọn orilẹ-ède ni ilẹ wọn, olukuluku
gẹgẹ bi ohùn rẹ̀; gẹgẹ bi idile wọn, li
orilẹ-ède wọn.
6 Ati awọn ọmọ Hamu; Kuṣi, ati
Misraimu, ati Futi, ati Kenaani.
7 Ati awọn ọmọ Kuṣi; Seba, ati Hafila,
ati Sabta, ati Raama, ati Sabteka; ati
awọn ọmọ Raama; Ṣeba, ati Dedani.
8 Kuṣi si bì Nimrodu: on si bẹrẹ si idi
alagbara li aiye.
9 On si ṣe ogbóju ọdẹ niwaju OLUWA:
nitori na li a ṣe nwipe, Gẹgẹ bi Nimrodu
ogbóju ọdẹ niwaju OLUWA.
10 Ipilẹṣẹ ijọba rẹ̀ ni Babeli, ati Ereki,
ati Akkadi, ati Kalne, ni ilẹ Ṣinari.
11 Lati ilẹ na ni Aṣṣuri ti jade lọ, o
si tẹ̀ Ninefe, ati ilu Rehoboti, ati Kala
dó.

Digitized by Google

12 Ati Reseni lagbedemeji Ninefe on
Kala: eyi na ni ilu nla.
13 Misraimu si bí Ludimu, ati Anami-
mu, ati Lehabimu, ati Naftuhimu.
14 Ati Patrusimu, ati Kasluhimu (lati
ọdọ ẹniti Filistimu ti wá), ati Kaftorimu.
15 Kenaani si bí Sidoni akọbi rẹ̀, ati
Heti,
16 Ati awọn ara Jebusi, ati awọn ara
Amori, ati awọn ara Girgaṣi,
17 Ati awọn ara Hiffi, ati awọn ara Arki,
ati awọn ara Sini,
18 Ati awọn ara Arfadi, ati awọn ara
Semari, ati awọn ara Hamati; lẹhin eyini
ni idile awọn ara Kenaani tàn kalẹ.
19 Ati àgbegbe awọn ara Kenaani ni
Sidoni, bi o ti mbọ̀wa Gerari, titi de Gasa;
bi o ti nlọ si Sodomu, ati Gomorra, ati
Adma, ati Seboimu, titi dé Laṣa.
20 Awọn wọnyi li ọmọ Hamu, gẹgẹ bi
idile wọn, gẹgẹ bi ohùn wọn ni ilẹ wọn,
ati li orilẹ-ède wọn.
21 Fun Ṣemu pẹlu, baba gbogbo awọn
ọmọ Eberi, ẹgbọn Jafeti ati fun on li a
bimọ.
22 Awọn ọmọ Ṣemu: Elamu, ati Aṣṣuri,
ati Arfaksadi, ati Ludi, ati Aramu.
23 Ati awọn ọmọ Aramu; Usi, ati Huli,
ati Geteri, ati Maṣi.
24 Arfaksadi si bí Ṣela; Ṣela si bí Eberi.
25 Ati fun Eberi li a bí ọmọkọnrin
meji; orukọ ekini ni Pelegi; nitori nigba
ọjọ́ rẹ̀ ni ilẹ yà; orukọ arakọnrin rẹ̀ ni
Joktani.
26 Joktani si bí Almodadi, ati Ṣelefi, ati
Hasarmafeti, ati Jera,
27 Ati Hadoramu, ati Usali, ati Dikla,
28 Ati Obali, ati Abimaeli, ati Ṣeba,
29 Ati Ofiri, ati Hafila, ati Jobabu:
gbogbo awọn wọnyi li ọmọ Joktani.
30 Ibugbe wọn si ti Meṣa lọ, bi iwọ ti
nlọ si Sefari, oke kan ni ìla-õrùn.
31 Awọn wọnyi li ọmọ Ṣemu, gẹgẹ bi
idile wọn, gẹgẹ bi ohùn wọn, ni ilẹ wọn, li
orile-ède wọn.
32 Wọnyi ni idile awọn ọmọ Noa, gẹge
bi iran wọn, li orilẹ-ède wọn: lati ọwọ́ awọn
wọnyi wá li a ti pín orilẹ-ède aiye lẹhin
kíkun-omi.

## ORI 11.

GBOGBO aiye si jẹ ède kan, ati ọ̀rọ
kan.
2 O si ṣe, bi nwọn ti nrìn lati ìha ìla-
õrùn lọ, ti nwọn ri pẹtẹlẹ kan ni ilẹ Ṣinari;
nwọn si tẹdo sibẹ̀.
3 Nwọn si wi, ikini si ekeji pe, Ẹ wá
na, ẹ jẹ ki a mọ briki. ki a si sun wọn jina.
Briki ni nwọn ni li okuta, ọ̀da-ilẹ ni nwọn
si nfi ṣe ọrọ.
4 Nwọn si wipe, Ẹ wá na, ẹ jẹ ki a tẹ̀
ilu kan dó, ki a si mọ ile-iṣọ kan, ori eyiti
yio si kàn ọrun; ki a si li orukọ, ki a má
ba tuka kiri sori ilẹ gbogbo.
5 OLUWA si sọkalẹ wá iwò ilu ati ile-iṣọ
na, ti awọn ọmọ enia nkọ̀.
6 OLUWA si wipe, Kiye si i, ọkan li
awọn enia, ède kan ni gbogbo wọn ni; eyi
ni nwọn bẹ̀rẹ si iṣe: njẹ nisisiyi kò sí
ohun ti a o le igbà lọwọ wọn ti nwọn ti rò
lati ṣe.
7 Ẹ wá na, ẹ jẹ ki a sọkalẹ lọ, ki a dà
wọn li ède rú nibẹ̀, ki nwọn ki o máṣe gbedè
ara wọn mọ̀.
8 Bẽli OLUWA tú wọn ká lati ibẹ̀ lọ si
ori ilẹ gbogbo: nwọn si ṣíwọ ilu ti nwọn
ntẹdó.
9 Nitorina li a ṣe npè orukọ ilu na ni
Babeli; nitori ibẹ̀ li OLUWA gbe dà ède
araiye rú, lati ibẹ̀ lọ OLUWA si tú wọn ká
kiri si ori ilẹ gbogbo.
10 Wọnyi ni iran Ṣemu: Ṣemu jẹ ẹni
ọgọrun ọdún, o si bí Arfaksadi li ọdún keji
lẹhin kíkun-omi.
11 Ṣemu si wà li ẹ̃dẹgbẹta ọdún, lẹhin
igbati o bí Arfaksadi tan, o si bí ọmọkọnrin
ati ọmọbirin.
12 Arfaksadi si wà li arundilogoji ọdún,
o si bí Ṣela:
13 Arfaksadi si wà ni irinwo ọdún o le
mẹta, lẹhin igbati o bí Ṣela tan, o si bí
ọmọkọnrin ati ọmọbirin.
14 Ṣela si wà ni ọgbọ̀n ọdún, o si bí
Eberi:
15 Ṣela si wà ni irinwo ọdún o le mẹta
lẹhin ti o bí Eberi tan, o si bí ọmọkọnrin
ati ọmọbirin.
16 Eberi si wà li ọgbọ̀n ọdún o le mẹrin,
o si bí Pelegi:
17 Eberi si wà ni irinwo ọdún o le ọgbọ̀n
lẹhin igbati o bí Pelegi tan, o si bí ọmọ-
kọnrin ati ọmọbirin.
18 Pelegi si wà li ọgbọ̀n ọdún, o si bi
Reu:
19 Pelegi si wà ni igba ọdún o le mẹsan
lẹhin igbati o bí Reu tan, o si bí ọmọkọnrin
ati ọmọbirin.
20 Reu si wà li ọgbọ̀n ọdún o le meji, o
si bí Serugu:
21 Reu si wà ni igba ọdún o le meje,
lẹhin igbati o bí Serugu tan, o si bí ọmọ-
kọnrin ati ọmọbirin.

Digitized by Google

22 Serugu si wà li ọgbọ̀n ọdún, o si bí
Nahori:
23 Serugu si wà ni igba ọdún lẹhin igba
ti o bí Nahori tan, o si bí ọmọkọnrin ati
ọmọbirin.
24 Nahori si jẹ ẹni ọdún mọkanlelọgbọ̀n
o si bí Tera:
25 Nahori si wà li ọgọfa ọdún o dí ọkan,
lẹhin igbati o bí Tera tan, o si bí ọmọkọnrin
ati ọmọbirin.
26 Tera si wà li ãdọrin ọdún, o si bí
Abramu, Nahori, ati Harani.
27 Iran Tera si li eyi: Tera bi Abramu,
Nahori, ati Harani; Harani si bí Loti.
28 Harani si kú ṣaju Tera baba rẹ̀, ni
ilẹ ibi rẹ̀, ni Uri ti Kaldea.
29 Ati Abramu ati Nahori fẹ aya fun
ara wọn: orukọ aya Abramu ni Sarai; ati
orukọ aya Nahori ni Milka, ọmọbirin Hara-
ni, baba Milka, ati baba Iska,
30 Ṣugbọn Sarai yàgan; kò li ọmọ.
31 Tera si mu Abramu ọmọ rẹ̀, ati Loti,
ọmọ Harani, ọmọ ọmọ rẹ̀, ati Sarai aya ọmọ
rẹ̀, aya Abramu ọmọ rẹ̀; nwọn si ba wọn
jade kuro ni Uri ti Kaldea, lati lọ si ilẹ
Kenaani; nwọn si wá titi de Harani, nwọn
si joko sibẹ̀.
32 Ọjọ́ Tera si jẹ igba ọdún o le marun:
Tera si kú ni Harani.

## ORI 12.

OLUWA si ti wi fun Abramu pe, Jade
kuro ni ilẹ rẹ, ati kuro lọdọ awọn ará
rẹ, ati kuro ni ile baba rẹ, si ilẹ kan ti emi
o fi hàn ọ:
2 Emi o si sọ ọ di orilẹ-ède nla, emi o si
busi i fun ọ, emi o si sọ orukọ rẹ di nla;
ibukun ni iwọ o si jasi:
3 Emi o bukun fun awọn ti nsúre fun ọ,
ẹniti o nfi ọ ré li emi o si fi ré; ninu rẹ li a
o ti bukun fun gbogbo idile aiye.
4 Bẽli Abramu lọ. bi OLUWA ti sọ fun
u; Loti si ba a lọ: Abramu si jẹ ẹni àrun-
dilọgọrin ọdún nigbati o jade ni Harani.
5 Abramu si mu Sarai aya rẹ̀, ati Loti
ọmọ arakọnrin rẹ̀, ati gbogbo ini wọn ti
nwọn kojọ, enia gbogbo ti nwọn ní ni Ha-
rani, nwọn si jade lati lọ si ilẹ Kenaani; ni
ilẹ Kenaani ni nwọn si wá si.
6 Abramu si là ilẹ na kọja lọ si ibi ti a
npè ni Ṣekemu, si igbo More. Awọn ara
Kenaani si wà ni ilẹ na ni ìgbana.
7 OLUWA si fi ara hàn fun Abramu, o si
wipe, Irú-ọmọ rẹ li emi o fi ilẹ yi fun: nibẹ̀
li o si tẹ́ pẹpẹ fun OLUWA ti o fi ara hàn a.
8 O si sí kuro nibẹ̀ lọ si ori oke kan ni
ìha ìla-õrùn Beteli, o si pa agọ́ rẹ̀, Beteli
ni ìwọ-õrùn ati Hai ni ìla-õrùn: o si tẹ́
pẹpẹ kan nibẹ̀ fun OLUWA, o si kepè orukọ
OLUWA.
9 Abramu si nrìn lọ, o nlọ si ìha gusù
sibẹ̀.
10 Ìyan kan si mu ni ilẹ na: Abramu
si sọkalẹ lọ si Egipti lati ṣe atipo nibẹ̀; ni-
toriti ìyan na mu gidigidi ni ilẹ na.
11 O si ṣe, nigbati o kù si dẹdẹ lati wọ̀
Egipti, o wi fun Sarai aya rẹ̀ pe, Kiyesi i
nisisiyi, emi mọ̀ pe arẹwà obirin lati wò ni
iwọ:
12 Nitorina yio si ṣe, nigbati awọn ara
Egipti yio ri ọ, nwọn o wipe, aya rẹ̀ li
eyi: nwọn o si pa mi, ṣugbọn nwọn o dá
ọ si.
13 Mo bẹ̀ ọ, wipe, arabirin mi ni iwọ iṣe:
ki o le irọ̀ mi lọrùn nitori rẹ; ọkàn mi yio
si yè nitori rẹ.
14 O si ṣe nigbati Abramu de Egipti,
awọn ara Egipti wò obirin na pe arẹwà enia
gidigidi ni.
15 Awọn ijoye Farao pẹlu ri i, nwọn si
ròhin rẹ̀ niwaju Farao; a si mu obirin na
lọ si ile Farao.
16 O si nṣikẹ Abramu gidigidi nitori rẹ̀:
on si li agutan, ati akọ-malu, ati akọ-kẹtẹ-
kẹtẹ, ati iranṣẹkọnrin ati iranṣẹbirin, abo-
kẹtẹkẹtẹ, ati ibakasiẹ.
17 OLUWA si fi iyọnu nla yọ Farao ati
awọn ara ile rẹ̀ li ẹnu, nitori Sarai aya
Abramu.
18 Farao si pè Abramu, o wipe, ewo li
eyiti iwọ ṣe si mi yi? ẽṣe ti iwọ kò fi wi fun
mi pe, aya rẹ ni iṣe?
19 Eṣe ti iwọ fi wipe, arabirin mi ni iṣe?
bẽli emi iba fẹ ẹ li aya mi si: njẹ nisisiyi
wò aya rẹ, mu u; ki o si ma ba tirẹ lọ.
20 Farao si paṣẹ fun awọn ọkọnrin rẹ̀
nitori Abramu: nwọn si sìn i jade lọ, ati
aya rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o ni.

## ORI 13.

ABRAMU si goke lati Egipti wá, on, ati
aya rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o ni ati Loti
pẹlu rẹ̀, si ìha gusu.
2 Abramu si là gidigidi, li ẹran-ọ̀sin, ni
fadaka, ati ni wurà.
3 O si nrìn ìrin rẹ̀ lati ìha gusu lọ titi o
si fi de Beteli, de ibi ti agọ́ rẹ̀ ti wà ni iṣaju,
lagbedemeji Beteli on Hai.
4 Si ibi pẹpẹ ti o ti tẹ́ nibẹ̀ ni iṣãju: nibẹ̀
li Abramu si nkepè orukọ OLUWA.
5 Ati Loti pẹlu, ti o ba Abramu lọ, ni
agbo-ẹran, ati ọwọ́-eran, ati agọ́.

Digitized by Google

6 Ilẹ na kò si le igbà wọn, ki nwọn ki o
le igbé pọ̀: nitori ini wọn pọ̀, bẽni nwọn
kò si le gbé pọ̀.
7 Bẽni gbolohùn asọ̀ si wà lãrin awọn
darandaran Abramu, ati awọn darandaran
Loti: ati awọn ara Kenaani ati awọn enia
Perissi ngbé ilẹ na ni ìgba na.
8 Abramu si wi fun Loti pe, Emi bẹ̀ ọ,
máṣe jẹ ki gbolohùn asọ̀ ki o wà lãrin temi
tirẹ, ati lãrin awọn darandaran mi, ati
awọn darandaran rẹ; nitori pe ará li awa
iṣe.
9 Gbogbo ilẹ kọ́ eyi niwaju rẹ? emi bẹ̀
ọ, yà ara rẹ kuro lọdọ mi: bi iwọ ba pọ̀ si
apa òsi, njẹ emi o pọ̀ si ọtún; tabi bi iwọ
ba pọ̀ si apa ọtún, njẹ emi o pọ̀ si òsi.
10 Loti si gboju rẹ̀ si oke, o si wò gbo-
gbo àgbegbe Jordani, pe o li omi nibi gbo-
gbo, ki OLUWA ki o to pa Sodomu on Go-
morra run, bi ọgbà OLUWA, bi ilẹ Egipti,
bi iwọ ti mbọ̀wa si Soari.
11 Nigbana ni Loti yàn gbogbo àgbegbe
Jordani fun ara rẹ̀; Loti si nrìn lọ si ìha
ìla-õrùn: bẽni nwọn yà ara wọn, ekini kuro
lọdọ ekeji.
12 Abramu si joko ni ilẹ Kenaani, Loti
si joko ni ilu àgbegbe nì, o si pagọ́ rẹ̀ titi
de Sodomu.
13 Ṣugbọn awọn ọkọnrin Sodomu ṣe enia
buburu, ati ẹ̀lẹṣẹ gidigidi niwaju OLUWA.
14 OLUWA si wi fun Abramu, lẹhin igba-
ti Loti yà kuro lọdọ rẹ̀ tan pe, Gbé oju rẹ
soke nisisiyi, ki o si wò lati ibi ti o gbé wà
nì lọ, si ìha ariwa, ati si ìha gusu, si ìha
ìla-õrùn, at si ìha ìwọ-õrùn:
15 Gbogbo ilẹ ti o ri nì, iwọ li emi o sa
fi fun ati fun irú-ọmọ rẹ lailai.
16 Emi o si ṣe irú-ọmọ rẹ bi erupẹ ilẹ:
tobẽ bi o ba ṣepe enia kan ba le kà iye eru-
pẹ ilẹ, on li a o to le kaye irú-ọmọ rẹ pẹlu.
17 Dide, rìn ilẹ na já ni ìna rẹ̀, ati ni
ibú rẹ̀; nitori iwọ li emi o fi fun.
18 Nigbana ni Abramu ṣí agọ́ rẹ̀, o si
wá, o si joko ni igbo Mamre, ti o wà ni
Hebroni, o si tẹ́ pẹpẹ kan nibẹ̀ fun OLUWA.

## ORI 14.

O SI ṣe li ọjọ́ Amrafeli ọba Ṣinari, Arioku
ọba Ellasari, Kedorlaomeri ọba Elamu,
ati Tidali ọba awọn orilẹ-ède;
2 Ti nwọn ba Bera ọba Sodomu jagun,
pẹlu Birṣa ọba Gomorra, Ṣinabu ọba Adma,
ati Semeberi ọba Seboimu, pẹlu ọba Bela
(eyini ni Soari).
3 Gbogbo awọn wọnyi li o dapọ̀ li afoni-
foji Siddimu, ti iṣe Okun Iyọ̀.
4 Nwọn sìn Kedorlaomeri li ọdún meji-
la, li ọdún kẹtala nwọn ṣọ̀tẹ.
5 Li ọdún kẹrinla ni Kedorlaomeri, wá
ati awọn ọba ti o wà pẹlu rẹ̀, nwọn kọlu
awọn Refaimu ni Aṣteroti-Karnaimu, ati
awọn Susimu ni Hamu, ati awọn Emimu
ni pẹtẹlẹ Kiriataimu.
6 Ati awọn ara Hori li oke Seiri wọn,
titi o fi de igbo Parani, ti o wà niha ijù.
7 Nwọn si pada, nwọn si wá si Enmiṣpa-
ti, eyini ni Kadeṣi, nwọn si kọlu gbogbo
oko awọn ara Amaleki, ati awọn ara Amori
ti o tẹdo ni Haseson-tamari pẹlu.
8 Ọba Sodomu si jade, ati ọba Gomorra,
ati ọba Adma, ati ọba Seboimu, ati ọba
Bela, (eyini ni Soari;) nwọn si tẹgun si
ara wọn li afonifoji Siddimu;
9 Si Kedorlaomeri ọba Elamu, ati si
Tidali ọba awọn orilẹ-ède, ati Amrafeli ọba
Ṣinari, ati Arioku ọba Ellasari, ọba mẹrin
si marun.
10 Afonifoji Siddimu si jẹ kìki kòto
ọ̀da-ilẹ; awọn ọba Sodomu ati ti Gomorra
sá, nwọn si ṣubu nibẹ̀; awọn ti o si kù sá-
lọ si ori oke.
11 Nwọn si kó gbogbo ẹrù Sodomu on
Gomorra ati gbogbo onjẹ wọn, nwọn si ba
ti wọn lọ.
12 Nwọn si mu Loti ọmọ arakọnrin A-
bramu, ti ngbé Sodomu, nwọn si kó ẹrù
rẹ̀, nwọn si lọ.
13 Ẹnikan ti o sá asalà de, o si rò fun
Abramu Heberu nì; on sa tẹdo ni igbo
Mamre; ara Amori, arakọnrin Eṣkoli ati
arakọnrin Aneri: awọn wọnyi li o mba
Abramu ṣe pọ̀.
14 Nigbati Abramu gbọ́ pe a dì arakọn-
rin on ni igbẹkun, o kó awọn ọmọ ọdọ rẹ̀ ti
a ti kọ́, ti a bí ni ile rẹ̀ jade, ọrindinirun
enia o dí meji, o si lepa de Dani.
15 O si pín ara rẹ̀, on, pẹlu awọn ọmọ-
ọdọ rẹ̀, si wọn li oru, o si kọlù wọn, o si
lépa wọn de Hoba, ti o wà li apa òsi Da-
masku:
16 O si gbà gbogbo ẹrù na pada, o si
gbà Loti arakọnrin rẹ̀ pada pẹlu, ati ẹrù
rẹ̀, ati awọn obirin pẹlu, ati awọn enia.
17 Ọba Sodomu si jade lọ ipade rẹ̀ li àbọ
iṣẹgun Kedorlaomeri ati awọn ọba ti o pẹlu
rẹ̀, li afonifoji Ṣafe, ti iṣe Afonifoji Ọba.
18 Melkisedeki ọba Salemu si mu onjẹ
ati ọti waini jade wá: on a si ma ṣe alufa
Ọlọrun Ọga-ogo.
19 O si súre fun u, o si wipe, Ibukun ni
fun Abramu, ti Ọlọrún ọga-ogo, ẹniti o ni
ọrun on aiye.

Digitized by Google

20 Olubukun si li Ọlọrun ọga-ogo ti o fi
awọn ọta rẹ le ọ lọwọ. On si dá idamẹwa
ohun gbogbo fun u.
21 Ọba Sodomu si wi fun Abramu pe,
Dá awọn enia fun mi, ki o si mu ẹrù fun
ara rẹ.
22 Abramu si wi fun ọba Sodomu pe,
Mo ti gbé ọwọ́ mi soke si OLUWA, Ọlọrun
ọga-ogo, ti o ni ọrun on aiye,
23 Pe, emi ki yio mu lati finrin owu titi
dé okùn bàta, ati pe, emi ki yio mu ohun
kan ti iṣe tirẹ, ki iwọ ki o má ba wipe, Mo
sọ Abramu di ọlọrọ̀:
24 Bikoṣe kìki eyiti awọn ọdọmọkọnrin
ti jẹ, ati ipín ti awọn ọkọnrin ti o ba mi
lọ; Aneri, Eṣkoli, ati Mamre; jẹ ki nwọn
ki o mu ipín ti wọn.

## ORI 15.

LẸHIN nkan wọnyi ọ̀rọ OLUWA tọ̀ Abra-
mu wá li ojuran, wipe, Má bẹ̀ru,
Abramu; Emi li asà rẹ, ère nla rẹ gidigidi.
2 Abramu si wipe, OLUWA Ọlọrun, kini
iwọ o fi fun mi, emi sa nlọ li ailọmọ, Elie-
seri ti Damasku yi si ni ẹniti o ni ile mi?
3 Abramu si wipe, Wo o emi ni iwọ kò
fi irú-ọmọ fun: si wo o ibile mi, on li arole
mi.
4 Si wo o, ọ̀rọ OLUWA tọ̀ ọ wá, wipe,
Eleyi ki yio ṣe arole rẹ; bikoṣe ẹniti yio ti
inu ara rẹ jade, on ni yio ṣe arole rẹ.
5 O si mu u jade wá si gbangba, o si wi
pe, Gboju wò oke ọrun nisisiyi, ki o si kà
irawọ bi iwọ ba le kà wọn: o si wi fun u
pe, Bẽni irú-ọmọ rẹ yio ri.
6 O si gba OLUWA gbọ́; on si kà a si
fun u li ododo.
7 O si wi fun u pe, Emi li OLUWA ti o
mu ọ jade lati Uri ti Kaldea wá, lati fi ilẹ
yi fun ọ lati jogun rẹ̀.
8 O si wipe, OLUWA Ọlọrun, nipa bawo
li emi o fi mọ̀ pe emi o jogun rẹ̀?
9 O si wi fun u pe, Mu ẹgbọrọ malu ọlọ-
dun mẹta fun mi wá, ati ewurẹ ọlọdun
meta, ati àgbo ọlọdun mẹta, ati oriri kan,
ati ọmọ ẹiyẹle kan.
10 O si mu gbogbo nkan wọnyi wá sọdọ
rẹ̀, o si là wọn li agbedemeji, o si fi ẹ̀la
ekini kọju si ekeji: bikoṣe awọn ẹiyẹ ni
kò là.
11 Nigbati awọn ẹiyẹ si sọkalẹ wá si ori
oku wọnyi, Abramu lé wọn kuro.
12 O si ṣe nigbati õrùn nwọ̀ lọ, orun
ìjika kùn Abramu; si kiyesi i, ẹru bà a,
òkunkun biribiri si bò o.
13 On si wi fun Abramu pe, Mọ̀ nitõtọ
pe irú-ọmọ rẹ yio ṣe alejo ni ilẹ ti ki iṣe ti
wọn, nwọn o si sìn wọn, nwọn o si jẹ wọn
ni ìya ni irinwo ọdún;
14 Ati orilẹ-ède na pẹlu ti nwọn o ma
sìn, li emi o dá lẹjọ: lẹhin na ni nwọn o
si jade ti awọn ti ọrọ̀ pipọ̀.
15 Iwọ o si tọ̀ awọn baba rẹ lọ li alafia;
li ogbologbo ọjọ́ li a o sin ọ.
16 Ṣugbọn ni iran kẹrin, nwọn o si tun
pada wá nihinyi: nitori ẹ̀ṣẹ awọn ara A-
mori kò ti ikún.
17 O si ṣe nigbati õrùn wọ̀, òkunkun si
ṣú, kiye si i ileru elẽfin, ati iná fitila ti
nkọja lãrin ẹ̀la wọnni.
18 Li ọjọ́ na gan li OLUWA bá Abramu
dá majẹmu pe, irú-ọmọ rẹ ni mo fi ilẹ yi
fun, lati odò Egipti wá, titi o fi de odò nla
nì, odò Euferate:
19 Awọn enia Keni, ati awọn enia Ke-
nissi, ati awọn enia Kadmoni,
20 Ati awọn enia Hitti, ati awọn enia
Perissi, ati awọn Refaimu,
21 Ati awọn enia Amori, ati awọn enia
Kenaani, ati awọn Girgaṣi, ati awọn Jebusi.

## ORI 16.

SARAI, aya Abramu, kò bímọ fun u:
ṣugbọn o li ọmọ-ọdọ kan obirin, ara
Egipti, orukọ ẹniti ijẹ Hagari.
2 Sarai si wi fun Abramu pe, kiyesi i na,
OLUWA dá mi duro lati bímọ: emi bẹ̀ ọ,
wọle tọ̀ ọmọbirin ọdọ mi; o le ṣepe bọya
emi a ti ipasẹ rẹ̀ li ọmọ. Abramu si gbà
ohùn Sarai gbọ́.
3 Sarai, aya Abramu, si mu Hagari ọmọ-
birin ọdọ rẹ̀ ara Egipti na, lẹhin igbati
Abramu gbé ilẹ Kenaani li ọdún mẹwa, o
si fi i fun Abramu ọkọ rẹ̀ lati ma ṣe aya rẹ̀.
4 On si wọle tọ̀ Hagari, o si loyun:
nigbati o ri pe on loyun, oluwa rẹ̀ obirin
wa di ẹ̀gan li oju rẹ̀.
5 Sarai si wi fun Abramu pe, Ẹbi mi wà
lori rẹ: emi li o fi ọmọbirin ọdọ mi le ọ li
àiya; nigbati o si ri pe on loyun, mo di
ẹ̀gan li oju rẹ̀; ki OLUWA ki o ṣe idajọ lãrin
temi tirẹ.
6 Ṣugbọn Abramu wi fun Sarai pe Wò o,
ọmọbirin ọdọ rẹ wà li ọwọ́ rẹ: fi i ṣe bi o ti
tọ̀ li oju rẹ. Nigbati Sarai nfõró rẹ̀, o sá
lọ kuro lọdọ rẹ̀.
7 Angeli OLUWA si ri i li ẹba isun omi
ni ijù, li ẹba isun omi li ọ̀na Ṣuri.
8 O si wipe, Hagari ọmọbirin ọdọ Sarai,
nibo ni iwọ ti mbọ̀? nibo ni iwọ si nrè?
O si wipe, emi sá kuro niwaju Sarai oluwa
mi.

Digitized by Google

9 Angeli OLUWA na si wi fun u pe, Pada, lọ si ọdọ oluwa rẹ, ki o si tẹriba fun u.
10 Angeli OLUWA na si wi fun u pe, Ni bíbi emi o mu iru-ọmọ rẹ bísi i, a ki yio si le kà wọn fun ọ̀pọlọpọ.
11 Angeli OLUWA na si wi fun u pe, kiyesi i iwọ loyun, iwọ o si bí ọmọkọnrin, iwọ o si sọ orukọ rẹ̀ ni Iṣmaeli; nitoriti OLUWA ti gbọ́ ohùn arò rẹ.
12 Jagidijagan enia ni yio si ṣe; ọwọ́ rẹ̀ yio wà lara enia gbogbo, ọwọ́ enia gbogbo yio si wà lara rẹ̀: on o si ma gbe iwaju gbogbo awọn arakọnrin rẹ̀.
13 O si pè orukọ OLUWA ti o ba a sọ̀rọ ni, Iwọ Ọlọrun ti o ri mi: nitori ti o wipe, Emi ha wá ẹniti o ri mi kiri nihin?
14 Nitori na li a ṣe npè kanga na ni Beer-lahai-roi: kiyesi i, o wà li agbedemeji Kadeṣi on Beredi.
15 Hagari si bí ọmọkọnrin kan fun Abramu: Abramu si pè orukọ ọmọ ti Hagari bí ni Iṣmaeli.
16 Abramu si jẹ ẹni ẹrindilãdọrun ọdún, nigbati Hagari bí Iṣmaeli fun Abramu.

## ORI 17.

NIGBATI Abramu si di ẹni ọkandilọgọrun ọdún, OLUWA farahàn Abramu, o si wi fun u pe, Emi li Ọlọrun Olodumare; ma rìn niwaju mi, ki iwọ ki o si pé.
2 Emi o si ba ọ dá majẹmu mi, emi o si sọ ọ di pupọ̀ gidigidi.
3 Abramu si dojubolẹ; Ọlọrun si ba a sọ̀rọ pe,
4 Bi o ṣe ti emi ni, kiyesi i, majẹmu mi wà pẹlu rẹ, iwọ o si ṣe baba orilẹ-ède pupọ̀.
5 Bẹ̃li a ki yio si pe orukọ rẹ ni Abramu mọ́, bikoṣe Abrahamu li orukọ rẹ yio jẹ; nitoriti mo ti sọ ọ di baba orilẹ-ède pupọ̀.
6 Emi o si mu ọ bí si i pupọpupọ, ọ̀pọ orilẹ-ède li emi o si mu ti ọdọ rẹ wá, ati awọn ọba ni yio ti inu rẹ jade wá.
7 Emi o si gbe majẹmu mi kalẹ lãrin temi tirẹ, ati lãrin irú-ọmọ rẹ lẹhin rẹ ni iran-iran wọn, ni majẹmu aiyeraiye, lati ma ṣe Ọlọrun rẹ, ati ti irú-ọmọ rẹ lẹhin rẹ.
8 Emi o si fi ilẹ ti iwọ ṣe alejo nibẹ̀ fun ọ, ati fun irú-ọmọ rẹ lẹhin rẹ, gbogbo ilẹ Kenaani ni iní titi lailai; emi o si ma ṣe Ọlọrun wọn.
9 Ọlọrun si wi fun Abrahamu pe, Nitorina ki iwọ ki o ma pa majẹmu mi mọ́, iwọ, ati irú-ọmọ rẹ lẹhin rẹ ni iran-iran wọn.
10 Eyi ni majẹmu mi, ti ẹnyin o ma pamọ́ lãrin temi ti nyin, ati lãrin irú-ọmọ rẹ lẹhin rẹ; gbogbo ọmọkọnrin inu nyin li a o kọ ni ilà.
11 Ẹnyin o si kọ ara nyin ni ilà; on ni yio si ṣe àmi majẹmu lãrin temi ti nyin.
12 Ẹniti o ba si di ọmọkọnrin ijọ mẹjọ ninu nyin li a o kọ ni ilà, gbogbo ọmọkọnrin ni iran-iran nyin, ati ẹniti a bí ni ile, tabi ti a fi owo rà lọwọ alejo, ti ki iṣe irú-ọmọ rẹ.
13 Ẹniti a bí ni ile rẹ, ati ẹniti a fi owo rẹ rà, a kò le ṣe alaikọ ọ ni ilà: bẹ̃ni majẹmu mi yio si wà li ara nyin ni majẹmu aiyeraiye.
14 Ati ọmọkọnrin alaikọlà ti a kò kọ ni ilà ara rẹ̀, ọkàn na li a o si ké kuro ninu awọn enia rẹ̀, o dà majẹmu mi.
15 Ọlọrun si wi fun Abrahamu pe, Bi o ṣe ti Sarai, aya rẹ nì, iwọ ki yio pè orukọ rẹ̀ ni Sarai mọ́, bikoṣe Sara li orukọ rẹ̀ yio ma jẹ.
16 Emi o si busi i fun u, emi o si bùn ọ li ọmọkọnrin kan pẹlu lati ọdọ rẹ̀ wá, bẹ̃li emi o si busi i fun u, on o si ṣe iya ọ̀pọ orilẹ-ède; awọn ọba enia ni yio ti ọdọ rẹ̀ wá.
17 Nigbana li Abrahamu dojubolẹ, o si rẹrin, o si wi li ọkàn rẹ̀ pe, A o ha bímọ fun ẹni ọgọrun ọdún? Sara ti iṣe ẹni ãdọrun ọdún yio ha bímọ bi?
18 Abrahamu si wi fun Ọlọrun pe, Ki Iṣmaeli ki o wà lãye niwaju rẹ!
19 Ọlọrun si wipe, Sara, aya rẹ, yio bí ọmọkọnrin kan fun ọ nitõtọ; iwọ o si sọ orukọ rẹ̀ ni Isaaki: emi o fi idi majẹmu mi mulẹ pẹlu rẹ̀, ni majẹmu aiyeraiye, ati pẹlu irú-ọmọ rẹ̀ lẹhin rẹ̀.
20 Emi si ti gbọ́ adura rẹ fun Iṣmaeli: kiyesi i, emi o si busi i fun u, emi o si mu u bisi i, emi o si sọ ọ di pupọ̀ gidigidi; ijoye mejila ni on o bí, emi o si sọ ọ di orilẹ-ède nla:
21 Ṣugbọn majẹmu mi li emi o ba Isaaki dá, eniti Sara yio bí fun ọ li akoko iwoyi amọ́dun.
22 O si fi i silẹ, li ọ̀rọ iba a sọ, Ọlọrun si lọ soke kuro lọdọ Abrahamu.
23 Abrahamu si mu Iṣmaeli, ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, ati gbogbo awọn ọmọ-ọdọ ọkọnrin ti a bí ni ile rẹ̀, ati gbogbo awọn ti a fi owo rẹ̀ rà, gbogbo ẹniti iṣe ọkọnrin ninu awọn enia ile Abrahamu; o si kọ wọn ni ilà ara li ọjọ́ na gan, bi Ọlọrun ti sọ fun u.
24 Abrahamu si jẹ ẹni ọkandilọgọrun ọdún, nigbati a kọ ọ ni ilà ara rẹ̀.

Digitized by Google

25 Ati Iṣmaeli ọmọ rẹ̀ ọkọnrin jẹ ẹni ọdún mẹtala nigbati a kọ ọ ni ilà ara rẹ̀.
26 Li ọjọ́ na gan li a kọ Abrahamu ni ilà, ati Iṣmaeli ọmọ rẹ̀ ọkọnrin.
27 Ati gbogbo awọn ọkọnrin ile rẹ̀, ti a bi ninu ile rẹ̀, ati ti a si fi owo rà lọwọ alejò, ni a kọ ni ilà pẹlu rẹ̀.

## ORI 18.

OLUWA si farahàn a ni igbo Mamre: on si joko li ẹnu-ọ̀na agọ́ ni imõru ọjọ́:
2 O si gbé oju rẹ̀ soke, o wò, si kiyesi i, ọkọnrin mẹta duro li ẹba ọdọ rẹ̀: nigbati o si ri wọn, o sure lati ẹnu-ọ̀na agọ́ lọ ipade wọn, o si tẹriba silẹ.
3 O si wipe, OLUWA mi, njẹ bi mo ba ri ore-ọfẹ li oju rẹ, emi bẹ̀ ọ, máṣe kọja lọ kuro lọdọ ọmọ-ọdọ rẹ:
4 Jẹ ki a mu omi diẹ wá nisisiyi, ki ẹnyin ki o si wẹ̀ ẹsẹ̀ nyin, ki ẹnyin ki o si simi labẹ igi:
5 Emi o si mu onjẹ diẹ wá, ki ẹnyin si fi ọkàn nyin balẹ; lẹhin eyini ki ẹnyin ma kọja lọ: njẹ nitorina li ẹnyin ṣe tọ̀ ọmọ-ọdọ nyin wá. Nwọn si wipe, Ṣe bẽ bi iwọ ti wi.
6 Abrahamu si yara tọ̀ Sara lọ ninu agọ́, o wipe, Yara mu òṣuwọn iyẹfun daradara mẹta, ki o pò o, ki o si dín akara.
7 Abrahamu si sure lọ sinu agbo, o si mu ẹgbọrọ-malu kan ti o rọ̀ ti o dara, o fi fun ọmọkọnrin kan; on si yara lati sè e.
8 O si mu orí-amọ́, ati wàra, ati ẹgbọrọ malu ti o sè, o si gbé e kalẹ niwaju wọn: on si duro tì wọn li abẹ igi na, nwọn si jẹ ẹ.
9 Nwọn si bi i pe, nibo ni Sara aya rẹ wà? o si wipe, wò o ninu agọ́.
10 O si wipe, Emi o si tun pada tọ̀ ọ wá nitõtọ ni iwoyi amọ́dun; si kiyesi i, Sara aya rẹ yio li ọmọkọnrin kan. Sara si gbọ́ li ẹnu-ọ̀na agọ́ ti o wà lẹhin ọkọnrin na.
11 Njẹ Abrahamu on Sara gbó, nwọn si pọ̀ li ọjọ́; o si dẹkun ati ma ri fun Sara bi iwa obirin.
12 Nitorina Sara rẹrin ninu ara rẹ̀ wipe, Lẹhin igbati mo di ogbologbo tan, emi o ha li ayọ̀, ti oluwa mi si di ogbologbo pẹlu?
13 OLUWA si wi fun Abrahamu pe, Nitori kini Sara ṣe nrẹrin wipe, Emi o ha bímọ nitõtọ, ẹniti o ti gbó tán?
14 Ohun kan ha ṣoro fun OLUWA? li akoko ti a dá emi o pada tọ̀ ọ wà, ni iwoyi amọ́dun, Sara yio si li ọmọkọnrin kan.
15 Sara si sẹ, wipe, Emi kò rẹrin; nitoriti o bẹ̀ru. On si wipe, Bẹ̃kọ; ṣugbọn iwọ rẹrin.
16 Awọn ọkọnrin na si dide kuro nibẹ̀, nwọn kọju sihà Sodomu: Abrahamu si ba wọn lọ lati sìn wọn de ọ̀na.
17 OLUWA si wipe, Emi o ha pa ohun ti emi o ṣe mọ́ fun Abrahamu;
18 Nitori pe, Abrahamu yio sa di orilẹ-ède nla ati alagbara, ati gbogbo orilẹ-ède aiye li a o bukun fun nipasẹ rẹ̀?
19 Nitoriti mo mọ̀ ọ pe, on o fi aṣẹ fun awọn ọmọ rẹ̀ ati fun awọn ara ile rẹ̀ lẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o ma pa ọ̀na OLUWA mọ́ lati ṣe ododo ati idajọ; ki OLUWA ki o le mu ohun ti o ti sọ fun Abrahamu wá fun u.
20 OLUWA si wipe, Nitori ti igbe Sodomu on Gomorra pọ̀, ati nitori ti ẹ̀ṣẹ wọn pàpọju.
21 Emi o sọkalẹ lọ nisisiyi, ki nri bi nwọn tilẹ ṣe, gẹgẹ bi okikí igbe rẹ̀, ti o de ọdọ mi; bi bẹ si kọ emi o mọ̀.
22 Awọn ọkọnrin na si yi oju wọn pada kuro nibẹ̀, nwọn si lọ si Sodomu: ṣugbọn Abrahamu duro sibẹ̀ niwaju OLUWA.
23 Abrahamu si sunmọ ọdọ rẹ̀, o si wipe, Iwọ o ha run olododo pẹlu enia buburu?
24 Bọya ãdọta olododo yio wà ninu ilu na: iwọ o ha run u, iwọ ki yio ha dá ibẹ̀ na si nitori ãdọta olododo ti o wà ninu rẹ̀?
25 O dàri, ti iwọ o fi ṣe bi irú eyi, lati run olododo pẹlu enia buburu; ti awọn olododo yio fi dabi awọn enia buburu, o dàri: Onidajọ gbogbo aiye ki yio ha ṣe eyi ti o tọ́?
26 OLUWA si wipe, Bi mo ba ri ãdọta olododo ninu ilu Sodomu, njẹ emi o dá gbogbo ibẹ̀ si nitori wọn.
27 Abrahamu si dahùn o si wipe, Wò o nisisiyi, emi ti dawọle e lati ba OLUWA sọ̀rọ, emi ẹniti iṣe erupẹ ati ẽru.
28 Bọya marun a dí ninu ãdọta olododo na: iwọ o ha run gbogbo ilu na nitori marun? On si wipe, Bi mo ba ri marunlelogoji nibẹ̀, emi ki yio run u.
29 O si tun sọ fun u ẹ̀wẹ, o ni, Bọya, a o ri òji nibẹ̀, On si wipe, Emi ki o run u nitori òji.
30 O si tun wipe, Jọ̃, ki inu ki o máṣe bi OLUWA, emi o si ma wi: bọya a o ri ọgbọ̀n nibẹ̀. On si wipe, Emi ki yio run u bi mo ba ri ọgbọ̀n nibẹ̀.
31 O si wipe, Wò o na, emi ti dawọle e lati ba OLUWA sọ̀rọ: bọya a o ri ogun nibẹ̀. On si wipe, Emi ki yio run u nitori ogun.
32 O si wipe, Jọ̃, ki inu ki o máṣe bi

Digitized by Google

Oluwa, ẹkanṣoṣo yi li emi o si wi mọ. Bọya, a o ri mẹwa nibẹ̀. On si wipe, Emi ki yio run u nitori mẹwa.

33 Oluwa si ba tirẹ̀ lọ, lojukanna bi o ti ba Abrahamu sọ̀rọ tan; Abrahamu si pada lọ si ibujoko rẹ̀.

## ORI 19.

AWỌN Angeli meji si wá si Sodomu li aṣalẹ; Loti si joko li ẹnu-bode Sodomu: bi Loti si ti ri wọn, o dide lati pade wọn: o si dojubolẹ;

2 O si wipe, Kiyesi i nisisiyi, ẹnyin oluwa mi, emi bẹ̀ nyin, ẹ yà si ile ọmọ-ọdọ nyin, ki ẹ si wọ̀, ki ẹ si wẹ ẹsẹ̀ nyin, ẹnyin o si dide ni kùtukutu, ki ẹ si ma ba ti nyin lọ. Nwọn si wipe, Ndao; ṣugbọn awa o joko ni igboro li oru oni.

3 O si rọ̀ wọn gidigidi; nwọn si yà tọ̀ ọ, nwọn si wọ̀ inu ile rẹ̀; o si sè àse fun wọn, o si dín àkara alaiwu fun wọn, nwọn si jẹ.

4 Ṣugbọn ki nwọn ki o to dubule, awọn ọkọnrin ara ilu na, awọn ọkọnrin Sodomu, nwọn yi ile na ká, ati àgba ati ewe, gbogbo enia lati ori igun mẹrẹrin wá.

5 Nwọn si pè Loti, nwọn si bi i pe, Nibo li awọn ọkọnrin ti o tọ̀ ọ wá li alẹ yi wà? mu wọn jade fun wa wá, ki awa ki o le mọ̀ wọn.

6 Loti si jade tọ̀ wọn lọ li ẹnu-ọ̀na, o si sé ilẹkun lẹhin rẹ̀.

7 O si wipe, Arakọnrin, emi bẹ̀ nyin, ẹ máṣe hùwa buburu bẹ̃.

8 Kiyesi i nisisiyi, emi li ọmọbirin meji ti kò ti imọ̀ ọkọnrin: emi bẹ̀ nyin, ẹ jẹ ki nmu wọn jade tọ̀ nyin wá, ki ẹnyin ki o si fi wọn ṣe bi o ti tọ́ loju nyin: ṣugbọn awọn ọkọnrin wọnyi ṣa ni ki ẹ má ṣe ni nkan; nitorina ni nwọn sa ṣe wá si abẹ orule mi.

9 Nwọn si wipe, Bì sẹhin. Nwọn si tun wipe, Eyiyi wá iṣe atipo, on si fẹ iṣe onidajọ: njẹ iwọ li a o tilẹ ṣe ni buburu jù wọn lọ. Nwọn si rọlù ọkọnrin na, ani Loti, nwọn si sunmọ ọ lati fọ́ ilẹkun.

10 Ṣugbọn awọn ọkọnrin na nà ọwọ́ wọn, nwọn si fà Loti mọ́ ọdọ sinu ile, nwọn si ti ilẹkun.

11 Nwọn si bù ifọju lù awọn ọkọnrin ti o wà li ẹnu-ọ̀na ile na, ati ewe ati àgba: bẹ̃ni nwọn dá ara wọn li agara lati ri ẹnu-ọ̀na.

12 Awọn ọkọnrin na si wi fun Loti pe, Iwọ ni ẹnikan nihin pẹlu? ana rẹ ọkọnrin, ati awọn ọmọ rẹ ọkọnrin, ati awọn ọmọ rẹ obirin, ati ohunkohun ti iwọ ni ni ilu, mu wọn jade kuro nihinyi:

13 Nitori awa o run ibi yi, nitori ti igbe wọn ndi pupọ̀ niwaju Oluwa; Oluwa si rán wa lati run u.

14 Loti si jade, o si sọ fun awọn ana rẹ̀ ọkọnrin, ti nwọn gbe awọn ọmọbirin rẹ̀ ni iyawo, o wipe, Ẹ dide, ẹ jade kuro nihinyi; nitoriti Oluwa yio run ilu yi. Ṣugbọn o dabi ẹlẹtàn loju awọn ana rẹ̀.

15 Nigbati ọ̀yẹ si nla, nigbana li awọn angeli na le Loti ni ire wipe, Dide, mu aya rẹ, ati awọn ọmọbirin rẹ mejeji ti o wà nihin; ki iwọ ki o má ba run ninu ìya ẹ̀ṣẹ ilu yi.

16 Nigbati o si nlọra, awọn ọkọnrin na nawọ mu u li ọwọ́ ati ọwọ́ aya rẹ̀, ati ọwọ́ ọmọbirin rẹ̀ mejeji; Oluwa sa ṣãnu fun u: nwọn si mu u jade, nwọn si fi i sẹhin odi ilu na.

17 O si se nigbati nwọn mu wọn jade sẹhin odi tan, li o wipe, Sá asalà fun ẹmi rẹ; máṣe wò ẹhin rẹ, bẹ̃ni ki iwọ ki o máṣe duro ni gbogbo pẹtẹlẹ; sá asalà lọ si ori oke, ki iwọ ki o má ba ṣegbe.

18 Loti si wi fun wọn pe, Bẹ̃kọ, oluwa mi:

19 Kiyesi i na, ọmọ-ọdọ rẹ ti ri ore-ọfẹ gbà li oju rẹ, iwọ si ti gbe ãnu rẹ ga, ti iwọ ti fi hàn mi ni gbigbà ẹmi mi là; ṣugbọn emi ki yio le salọ si ori oke, ki ibi ki o má ba bá mi nibẹ̀, ki emi ki o má ba kú.

20 Kiyesi i na, ilu yi sunmọ tosi lati sá si, kekere si ni: jọ̃, jẹ ki nsalà si ibẹ, (kekere ha kọ?) ọkàn mi yio si yè.

21 O si wi fun u pe, Wò o, mo gbà fun ọ niti ohun kan yi pẹlu pe, emi ki yio run ilu yi, nitori eyiti iwọ ti sọ.

22 Yara, salà sibẹ̀; nitori emi kò le ṣe ohun kan titi iwọ o fi de ibẹ̀. Nitorina li a ṣe npè orukọ ilu na ni Soari.

23 Ọrùn là sori ilẹ nigbati Loti wọ̀ ilu Soari.

24 Nigbana li Oluwa rọ̀jo sulfuri (okuta ina) ati iná lati ọdọ Oluwa lati ọrun wá si ori Sodomu on Gomorra:

25 O si run ilu wọnni, ati gbogbo Pẹtẹlẹ, ati gbogbo awọn ara ilu wọnni, ati ohun ti o hù jade ni ilẹ.

26 Ṣugbọn aya rẹ̀ bojuwò ẹhin lẹhin rẹ̀, o si di ọwọ̀n iyọ̀.

27 Abrahamu si dide ni kutukutu owurọ̀, o lọ si ibi ti o gbé duro niwaju Oluwa:

28 O si wò ìha Sodomu on Gomorra, ati ìha gbogbo ilẹ àgbegbe wọnni, o si

Digitized by Google

wò o, si kiyesi i, ẽfi ilẹ na rú soke bi ẽfi
ileru.
29 O si ṣe nigbati Ọlọrun run ilu àgbe-
gbe wọnni ni Ọlọrun ranti Abrahamu, o si
rán Loti jade kuro lãrin iparun na, nigbati
o run ilu wọnni ninu eyiti Loti gbé ti
joko.
30 Loti si jade kuro ni Soari: o si ngbé
ori oke, ati awọn ọmọbirin rẹ̀ mejeji pẹlu
rẹ̀; nitoriti o bẹ̀ru ati gbé Soari: o si ngbé
inu ihò, on ati awọn ọmọbirin rẹ̀ mejeji.
31 Eyi akọbi si wi fun atẹle pe, Baba
wa gbó, kò si sí ọkọnrin kan li aiye mọ́ ti
yio wọle tọ̀ wa wá gẹgẹ bi iṣe gbogbo aiye.
32 Wá, jẹ ki a mu baba wa mu ọti-waini,
awa o si sùn tì i, ki a le ni irú-ọmọ lati ọdọ
baba wa.
33 Nwọn si mu baba wọn mu ọti-waini li
oru na: eyi akọbi wọle tọ̀ ọ, o si sùn ti
baba rẹ̀; on kò si mọ̀ igbati o dubulẹ, ati
igbati o dide.
34 O si ṣe, ni ijọ́ keji, ni ẹgbọn wi fun
aburo pe, kiyesi i, emi sùn tì baba mi li
oru aná: jẹ ki a si mu u mu ọti-waini li
oru yi pẹlu: ki iwọ ki o si wọle, ki o si
sùn tì i, ki awa ki o le ni irú-ọmọ lati ọdọ
baba wa.
35 Nwọn si mu baba wọn mu ọti-waini li
oru na pẹlu: aburo si dide, o si sùn tì i,
on kò si mọ̀ igbati o dubulẹ, ati igbati o
dide.
36 Bẽli awọn ọmọbirin Loti mejeji loyun
fun baba wọn.
37 Eyi akọ́bi si bí ọmọkọnrin kan, o si
pè orukọ rẹ̀ ni Moabu: on ni baba awọn
ara Moabu titi di oni.
38 Eyi atẹle, on pẹlu si bí ọmọkọnrin
kan, o si pè orukọ rẹ̀ ni Ben-ammi: on ni
baba awọn ọmọ Ammoni, titi di oni.

## ORI 20.

ABRAHAMU si ṣí lati ibẹ̀ lọ si ilẹ ìha
gusù, o si joko li agebedemeji Kadeṣi
on Ṣuri; o si ṣe atipo ni Gerari.
2 Abrahamu si wi niti Sara aya rẹ̀ pe,
Arabirin mi ni: Abimeleki ọba Gerari si
ranṣẹ, o si mu Sara.
3 Ṣugbọn Ọlọrun tọ̀ Abimeleki wá li
ojuran li oru, o si wi fun u pe, kiyesi i,
okú ni iwọ, nitori obirin ti iwọ mu nì;
nitori aya ọkọnrin kan ni iṣe.
4 Ṣugbọn Abimeleki kò sunmọ ọ: o si
wipe, OLUWA, iwọ o run orilẹ-ède olododo
pẹlu?
5 On kọ ha wi fun mi pe, arabirin mi ni
iṣe? on, obirin tikalarẹ̀ si wipe, arakọnrin
mi ni: li otitọ inu ati alaiṣẹ̀ ọwọ́ mi, ni
mo fi ṣe eyi.
6 Ọlorun si wi fun u li ojuran pe, Bẹ̃ni;
emi mọ̀ pe li otitọ inu rẹ ni iwọ ṣe eyi;
nitorina li emi si ṣe dá ọ duro ki o má ba
ṣẹ̀ mi: nitorina li emi kò ṣe jẹ ki iwọ ki o
fọwọkàn a.
7 Njẹ nitori na mu aya ọkọnrin na pada
fun u; woli li on sa iṣe, on o si gbadura
fun ọ, iwọ o si yè: bi iwọ kò ba si mu u
pada, ki iwọ ki o mọ̀ pe, kikú ni iwọ o kú,
iwọ ati gbogbo ẹniti o jẹ tirẹ.
8 Nitorina Abimeleki dide ni kutukutu
owurọ̀, o si pè gbogbo awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀, o
si wi gbogbo nkan wọnyi li eti wọn: ẹ̀ru
si bà awọn enia na gidigidi.
9 Nigbana li Abimeleki pè Abrahamu, o
si wi fun u pe, Kili o ṣe si wa yi? ẹ̀ṣẹ kini
mo ṣẹ̀ ọ, ti iwọ fi mu ẹ̀ṣẹ nla wá si ori mi,
ati si ori ijọba mi? iwọ hùwa si mi ti a ki
ba hù.
10 Abimeleki si wi fun Abrahamu pe,
Kini iwọ ri, ti iwọ fi ṣe nkan yi?
11 Abrahamu si wipe, Nitoriti mo rò
pe, nitõtọ ẹ̀ru Ọlọrun kò sí nihinyi; nwọn o
si pa mi nitori aya mi.
12 Ati pẹlupẹlu nitõtọ arabirin mi ni
iṣe, ọmọbirin baba mi ni, ṣugbọn ki iṣe
ọmọbirin iya mi; o si di aya mi.
13 O si ṣe nigbati Ọlọrun mu mi rìn kiri
lati ile baba mi wá, on ni mo wi fun u pe,
eyi ni ore rẹ ti iwọ o ma ṣe fun mi; nibi-
kibi ti awa o gbé de, ma wi nipa ti emi pe,
arakọnrin mi li on.
14 Abimeleki si mu agutan, ati akọma-
lu, ati iranṣẹkọnrin, ati iranṣẹbirin, o si fi
wọn fun Abrahamu, o si mu Sara, aya rẹ̀,
pada fun u.
15 Abimeleki si wipe, Kiyesi i, ilẹ mi
niyi niwaju rẹ: joko nibiti o wù ọ.
16 O si wi fun Sara pe, Kiyesi i, mo fi
ẹgbẹrun ìwọn fadaka fun arakọnrin rẹ:
kiyesi i, on ni ibojú fun ọ fun gbogbo awọn
ti o wà lọdọ rẹ, ati niwaju gbogbo awọn
ẹlomiran li a da ọ lare.
17 Abrahamu si gbadura si Ọlọrun: Ọ-
lọrun si mu Abimeleki li ara dá, ati aya rẹ̀,
ati awọn ọmọbirin-ọdọ rẹ̀; nwọn si bimọ.
18 Nitori OLUWA ti sé inu awọn ara ile
Abimeleki pinpin, nitori ti Sara, aya Abra-
hamu.

## ORI 21.

OLUWA si bẹ̀ Sara wò bi o ti wi, OLUWA
si ṣe fun Sara bi o ti sọ.
2 Sara si loyun, o si bí ọmọkọnrin kan

Digitized by Google

fun Abrahamu li ogbologbo rẹ̀, li akokò
igbati Ọlọrun dá fun u.
3 Abrahamu si pè orukọ ọmọ rẹ̀ ti a bí
fun u, ni Isaaki, ẹniti Sara bí fun u.
4 Abrahamu si kọ Isaaki ọmọ rẹ̀ ni ilà,
nigbati o di ọmọ ijọ́ mẹjọ, gẹgẹ bi Ọlọrun
ti fi aṣẹ fun u.
5 Abrahamu si jẹ ẹni ọgọrun ọdún, ni-
gbati a bí Isaaki ọmọ rẹ̀ fun u.
6 Sara si wipe, Ọlọrun pa mi lẹrin;
gbogbo ẹniti o gbọ́ yio si rẹrin pẹlu mi.
7 O si wipe, Tani iba wi fun Abrahamu
pe, Sara yio fi ọmú fun ọmọ mu? mo sá bí
ọmọ kan fun u li ogbologbo rẹ̀.
8 Ọmọ na si dàgba, a si já a li ẹnu ọmú:
Abrahamu si sè àse nla li ọjọ́ na ti a já
Isaaki li ẹnu ọmú.
9 Sara si ri ọmọ Hagari, ara Egipti, ti o
bí fun Abrahamu, o nfi i rẹrin.
10 Nitorina li o ṣe wi fun Abrahamu pe,
Lé ẹrubirin yi jade ti on ti ọmọ rẹ̀: nitoriti
ọmọ ẹrubirin yi ki yio ṣe arole pẹlu Isaaki,
ọmọ mi.
11 Ọrọ yi si buru gidigidi li oju Abra-
hamu nitori ọmọ rẹ̀.
12 Ọlọrun si wi fun Abrahamu pa, Máṣe
jẹ ki o buru li oju rẹ nitori ọmọdekọnrin
na, ati nitori ẹrubirin rẹ; ni gbogbo eyiti
Sara sọ fun ọ, fetisi ohùn rẹ̀; nitori ninu
Isaaki li a o ti pè irú-ọmọ rẹ.
13 Ati ọmọ ẹrubirin na pẹlu li emi o sọ
di orilẹ-ède, nitori irú-ọmọ rẹ ni iṣe.
14 Abrahamu si dide ni kutukutu owu-
rọ̀, o mu àkara ati ìgo omi kan, o fi fun
Hagari, o gbé e lé e li ejika, ati ọmọ na, o
si lé e jade: on si lọ o nrìn kakiri ni ijù
Beer-ṣeba.
15 Omi na si tán ninu ìgo, o si sọ̀ ọmọ
na si abẹ ìgboro kan.
16 O si lọ o joko kọju si i, li ọ̀na jijìn
rére, o tó bi itafa si kan: nitori ti o wipe,
Ki emi má ri ikú ọmọ na. O si joko kọju
si i, o gbé ohùn rẹ̀ soke, o nsọkun.
17 Ọlọrun si gbọ́ ohùn ọmọdekọnrin na:
angeli Ọlọrun si pè Hagari lati ọrun wá, o
bi i pe, Kili o ṣe ọ, Hagari? máṣe bẹ̀ru;
nitori ti Ọlọrun ti gbọ́ ohùn ọmọdekọnrin
na nibiti o gbé wà.
18 Dide, gbé ọmọdekọnrin na, ki o si
dì i mu; nitori ti emi o sọ ọ di orilẹ-ède
nla.
19 Ọlọrun si ṣí i li oju, o si ri kanga omi
kan; o lọ o si pọnmi kún ìgo na, o si fi
fun ọmọdekọnrin na mu.
20 Ọlọrun si wà pẹlu ọmọdekọnrin na;
o si dàgba, o si joko ni ijù, o di tafatafa.
21 O si joko ni ijù Parani: iya rẹ̀ si fẹ́
obirin fun u lati ilẹ Egipti wá.
22 O si ṣe li akokò na, ni Abimeleki ati
Fikoli, olori ogun rẹ̀, wi fun Abrahamu
pe, Ọlọrun pẹlu rẹ ni gbogbo ohun ti iwọ
nṣe.
23 Njẹ nisisiyi fi Ọlọrun bura fun mi
nihinyi pe iwọ ki yio ṣe ẹ̀tan si mi, tabi si
ọmọ mi, tabi si ọmọ-ọmọ mi: ṣugbọn gẹgẹ
bi iṣeun ti mo ṣe si ọ, bẽni iwọ o si ṣe si
mi, ati si ilẹ ti iwọ ti ṣe atipo ninu rẹ̀.
24 Abrahamu si wipe, emi o bura.
25 Abrahamu si ba Abimeleki wi nitori
kanga omi kan, ti awọn ọmọ-ọ̀dọ Abimele-
ki fi agbara gbà.
26 Abimeleki si wipe, emi kò mọ̀ ẹniti o
ṣe nkan yi: bẽni iwọ kò sọ fun mi, bẽli emi
kò gbọ́, bikoṣe loni.
27 Abrahamu si mu agutan, ati akọma-
lu, o fi wọn fun Abimeleki; awọn mejeji
si dá majẹmu.
28 Abrahamu si yà abo ọdọ-agutan meje
ninu agbo si ọ̀tọ fun ara wọn.
29 Abimeleki si bi Abrahamu pe, kili a
le mọ̀ abo ọdọ-agutan meje ti iwọ yà si ọ̀tọ
fun ara wọn yi si?
30 O si wipe, nitori abo ọdọ-agutan
meje yi ni iwọ o gbà lọwọ mi, ki nwọn ki o
le ṣe ẹrí mi pe, emi li o wà kanga yi.
31 Nitorina li o ṣe pè ibẹ̀ na ni Beer-
ṣeba; nitori nibẹ̀ li awọn mejeji gbé bura.
32 Bẽni nwọn si dá majẹmu ni Beer-
ṣeba: nigbana li Abimeleki dide, ati Fiko-
li, olori ogun rẹ̀, nwọn si pada lọ si ilẹ
awọn ara Filistia.
33 Abrahamu si lọ́ igi tamariski kan ni
Beer-ṣeba, nibẹ̀ li o si pè orukọ OLUWA,
Ọlọrun Aiyeraiye.
34 Abrahamu si ṣe atipo ni ilẹ awọn ara
Filistia li ọjọ́ pupọ̀.

## ORI 22.

O SI ṣe lẹhin nkan wọnyi ni Ọlọrun dán
Abrahamu wò, o si wi fun u pe, Abra-
hamu: on si dahùn pe, Emi niyi.
2 O si wi fun u pe, Mu ọmọ rẹ nisisiyi,
Isaaki, ọmọ rẹ na kanṣoṣo, ti iwọ fẹ́, ki
iwọ ki o si lọ si ilẹ Moria; ki o si fi i rubọ
sisun nibẹ̀ lori ọkan ninu oke ti emi o sọ
fun ọ.
3 Abrahamu si dide ni kutukutu owurọ̀,
o si dì kẹtẹkẹtẹ rẹ̀ ni gãrì, o si mu meji
ninu awọn ọdọmọkọnrin rẹ̀ pẹlu rẹ̀, ati
Isaaki, ọmọ rẹ̀, o si là igi fun ẹbọ sisun
na, o si dide, o si lọ si ibi ti Ọlọrun sọ
fun u.

Digitized by Google

4 Ni ijọ́ kẹta Abrahamu si gbé oju rẹ̀ soke, o ri ibẹ̀ na li okere.
5 Abrahamu si wi fun awọn ọdọmọkọnrin rẹ̀, pe, Ẹnyin joko nihin pẹlu kẹtẹkẹtẹ; ati emi ati ọmọ yi yio lọ si ọhún ni, a o si gbadura, a o si tun pada tọ̀ nyin wá.
6 Abrahamu si mu igi ẹbọ sisun na, o si dì i rù Isaaki, ọmọ rẹ̀; o si mu iná li ọwọ́ rẹ̀, ati ọbẹ; awọn mejeji si jùmọ nlọ.
7 Isaaki si sọ fun Abrahamu baba rẹ̀, o si wipe, Baba mi: on si wipe, Emi niyi, ọmọ mi. On si wipe, Wò iná on igi; ṣugbọn nibo li ọdọ-agutan ẹbọ sisun na gbé wà?
8 Abrahamu si wipe, Ọmọ mi, Ọlọrun tikalarẹ̀ ni yio pèse ọdọ-agutan fun ẹbọ sisun: bẽli awọn mejeji jùmọ nlọ.
9 Nwọn si de ibi ti Ọlọrun ti wi fun u; Abrahamu si tẹ́ pẹpẹ kan nibẹ̀, o si to igi rere, o si dì Isaaki ọmọ rẹ̀, o si dá a bulẹ li ori pẹpẹ lori igi na.
10 Abrahamu si nawọ rẹ̀, o si mu ọbẹ na lati dúmbu ọmọ rẹ̀.
11 Angeli Oluwa nì si kọ si i lati ọrun wá, o wipe, Abrahamu, Abrahamu: o si dahùn pe, Emi niyi.
12 O si wipe, Máṣe fọwọkàn ọmọde nì, bẽni iwọ kò gbọdọ ṣe e ni nkan: nitori nisisiyi emi mọ̀ pe iwọ bẹ̀ru Ọlọrun, nigbati iwọ kò ti dù mi li ọmọ rẹ, ọmọ rẹ na kanṣoṣo.
13 Abrahamu si gbé oju rẹ̀ soke, o wò, si kiyesi i, lẹhin rẹ̀, àgbo kan ti o fi iwo rẹ̀ há ni pantiri: Abrahamu si lọ o mu àgbo na, o si fi i rubọ sisun ni ipò ọmọ rẹ̀.
14 Abrahamu si pè orukọ ibẹ̀ na ni Jehofajire: bi a ti nwi titi di oni yi, Li oke Oluwa li a o gbe ri i.
15 Angeli Oluwa nì si kọ si Abrahamu lati ọrun wá lẹrinkeji,
16 O si wipe, Emi tikalami ni mo fi bura, li Oluwa wi, nitori bi iwọ ti ṣe nkan yi, ti iwọ kò si dù mi li ọmọ rẹ, ọmọ rẹ na kanṣoṣo:
17 Pe, ni bibukún emi o bukún fun ọ, ati ni bíbisi emi o mu irú-ọmọ rẹ bisi i bi irawọ oju-ọrun, ati bi iyanrin eti okun; irú-ọmọ rẹ ni yio si ni ẹnubode awọn ọta wọn;
18 Ati ninu irú-ọmọ rẹ li a o bukún fun gbogbo orilẹ-ède aiye: nitori ti iwọ ti gbà ohùn mi gbọ́.
19 Abrahamu si pada tọ̀ awọn ọdọmọkọnrin rẹ̀ lọ, nwọn si dide, nwọn si jùmọ lọ si Beer-ṣeba; Abrahamu si joko ni Beer-ṣeba.
20 O si ṣe, lẹhin nkan wọnyi, li a sọ fun Abrahamu pe, kiyesi i, Milka, on pẹlu si ti bimọ fun Nahori, arakọnrin rẹ;
21 Husi akọ́bi rẹ̀, ati Busi arakọnrin rẹ̀, ati Kemueli baba Aramu.
22 Ati Kesedi, ati Haso, ati Pildaṣi, ati Jidlafu, ati Betueli.
23 Betueli si bí Rebeka: awọn mẹjọ yi ni Milka bí fun Nahori, arakọnrin Abrahamu.
24 Ati àle rẹ̀, orukọ ẹniti ijẹ Rehuma, on pẹlu si bì Teba, ati Gahamu, ati Tahaṣi, ati Maaka.

## ORI 23.

SARA si di ẹni ẹtadilãdoje ọdún: iye ọdún aiye Sara li eyi.
2 Sara si kú ni Kirjat-arba; eyi na ni Hebroni ni ilẹ Kenaani: Abrahamu si wá lati ṣọ̀fọ Sara ati lati sọkun rẹ̀.
3 Abrahamu si dide kuro niwaju okú rẹ̀, o si sọ fun awọn ọmọ Heti, wipe,
4 Alejò ati atipo li emi iṣe lọdọ nyin: ẹ fun mi ni ilẹ-isinku lãrin nyin, ki emi ki o le sin okú mi kuro ni iwaju mi.
5 Awọn ọmọ Heti si dá Abrahamu lohùn, nwọn si wi fun u pe,
6 Oluwa mi, gbọ́ ti wa: alagbara ọmọalade ni iwọ lãrin wa: ninu ãyò bojì wa ni ki o sin okú rẹ; kò sí ẹnikẹni ninu wa ti yio fi ibojì rẹ̀ dù ọ, ki iwọ ki o má sin okú rẹ.
7 Abrahamu si dide duro, o si tẹriba fun awọn enia ilẹ na, fun awọn ọmọ Heti.
8 O si ba wọn sọ̀rọ wipe, Bi o ba ṣe pe ti inu nyin ni ki emi ki o sin okú mi kuro ni iwaju mi, ẹ gbọ́ ti emi, ki ẹ si bẹ̀ Efroni, ọmọ Sohari, fun mi,
9 Ki o le fun mi ni ihò Makpela, ti o ni, ti o wà li opinlẹ oko rẹ̀; li oju-owo ni ki o fifun mi, fun ilẹ-isinku lãrin nyin.
10 Efroni si joko lãrin awọn ọmọ Heti: Efroni, ọmọ Heti, si dá Abrahamu lohùn li eti gbogbo awọn ọmọ Heti, ani li eti gbogbo awọn ti nwọ̀ ẹnubode ilu rẹ̀ wipe,
11 Bẹ̀kọ, Oluwa mi, gbọ́ ti emi; mo fi oko na fun ọ, ati ihò ti o wà nibẹ̀, mo fi fun ọ: li oju awọn ọmọ awọn enia mi ni mo fi i fun ọ: sin okú rẹ.
12 Abrahamu si tẹriba niwaju awọn enia ilẹ na.
13 O si wi fun Efroni, li eti awọn enia ilẹ na pe, Njẹ bi iwọ o ba fi i fun mi, emi bẹ̀ ọ, gbọ́ ti emi: emi o san owo oko na fun ọ; gbà a lọwọ mi, emi o si sin okú mi nibẹ̀.

Digitized by Google

14 Efroni si da Abrahamu li ohùn, o wi
fun u pe,
15 Oluwa mi, gbọ́ ti emi : irinwo òṣuwọn
ṣekeli fadaka ni ilẹ jẹ ; kili eyini lãrin temi
tirẹ ? sa sin okú rẹ.
16 Abrahamu si gbọ́ ti Efroni ; Abraha-
mu si wọ̀n iye fadaka na fun Efroni, ti o sọ
li eti awọn ọmọ Heti, irinwo òṣuwọn ṣekeli
fadaka, ti o kọja lọdọ awọn oniṣòwo.
17 Oko Efroni ti o wà ni Makpela, ti o
wà niwaju Mamre, oko na, ati ihò ti o wà
ninu rẹ̀, ati gbogbo igi ti o wà ni oko na, ti
o wà ni gbogbo ẹba rẹ̀ yika, li a ṣe daju,
18 Fun Abrahamu ni ilẹ-ini, li oju awọn
ọmọ Heti, li oju gbogbo awọn ti nwọ̀ ẹnu-
bode ilu rẹ̀.
19 Lẹhin eyi li Abrahamu sin Sara, aya
rẹ̀, ninu ihò li oko Makpela, niwaju Mamre :
eyina ni Hebroni ni ilẹ Kenaani.
20 Ati oko na, ati ihò ti o wà nibẹ̀, li a
ṣe daju fun Abrahamu, ni ilẹ isinku, lati
ọwọ́ awọn ọmọ Heti wá.

## ORI 24.

ABRAHAMU si gbó, o si pọ̀ li ọjọ́ :
OLUWA si ti busi i fun Abrahamu li
ohun gbogbo.
2 Abrahamu si wi fun iranṣẹ rẹ̀, agba ile
rẹ̀ ti o ṣe olori ohun gbogbo ti o ni pe, Emi
bẹ̀ ọ, fi ọwọ rẹ si abẹ itan mi ;
3 Emi o si mu ọ fi OLUWA bura, Ọlọrun
ọrun, ati Ọlọrun aiye, pe iwọ ki yio fẹ́ aya
fun ọmọ mi ninu awọn ọmọbirin ara Ke-
naani, lãrin awọn ẹniti mo ngbé :
4 Ṣugbọn iwọ o lọ si ilẹ mi, ati si ọdọ
awọn ará mi, ki iwọ ki o si fẹ́ aya fun
Isaaki, ọmọ mi.
5 Iranṣẹ na si wi fun u pe, Bọya obirin
na ki yio fẹ́ ba mi wá si ilẹ yi : mo ha le
mu ọmọ rẹ pada lọ si ilẹ ti iwọ gbé ti wá ?
6 Abrahamu si wi fun u pe, Kiyesara ki
iwọ ki o má tun mu ọmọ mi pada lọ sibẹ̀.
7 OLUWA Ọlọrun ọrun, ti o mu mi lati
ile baba mi wá, ati lati ilẹ ti a bi mi, ẹniti
o sọ fun mi, ti o si bura fun mi, wipe, Irú-
ọmọ rẹ li emi o fi ilẹ yi fun ; on ni yio rán
angeli rẹ̀ ṣaju rẹ, iwọ o si fẹ́ aya lati ibẹ̀ fun
ọmọ mi wá.
8 Bi obirin na kò ba si fẹ́ tẹle ọ, njẹ
nigbana li ọrùn rẹ yio mọ́ kuro ni ibura mi
yi : ọkan ni, ki iwọ máṣe tun mu ọmọ mi
pada lọ sibẹ̀.
9 Iranṣẹ na si fi ọwọ́ rẹ̀ si abẹ itan Abra-
hamu oluwa rẹ̀, o si bura fun u nitori
ọ̀ran yi.
10 Iranṣẹ na si mu ibakasiẹ, mẹwa ninu
ibakasiẹ oluwa rẹ̀, o si lọ ; nitori pe li ọwọ́
rẹ̀ ni gbogbo ẹrù oluwa rẹ̀ wà : o si dide, o
si lọ si Mesopotamia, si ilu Nahori.
11 O si mu awọn ibakasiẹ rẹ̀ kunlẹ lẹhin
ode ilu na li ẹba kanga omi kan nigba
aṣalẹ, li akokò igbati awọn obirin ima jade
lọ pọnmi.
12 O si wipe, OLUWA, Ọlọrun Abrahamu
oluwa mi, emi bẹ̀ ọ, ṣe ọ̀na mi ni rere loni,
ki o si ṣe ore fun Abrahamu oluwa mi.
13 Kiyesi i, emi duro li ẹba kanga omi
yi ; awọn ọmọbirin ara ilu na njade wá lati
pọnmi :
14 Ki o si jẹ ki o ṣẹ pe, ọmọdan ti emi o
wi fun pe. Emi bẹ̀ ọ, sọ ladugbo rẹ kalẹ, ki
emi ki o mu ; ti on o si wipe, Mu, emi o si
fi fun awọn ibakasiẹ rẹ mu pẹlu : on na ni
ki o jẹ ẹniti iwọ yàn fun Isaaki iranṣẹ rẹ ;
nipa eyi li emi o si mọ̀ pe, iwọ ti ṣe ore fun
oluwa mi.
15 O si ṣe, ki on to pari ọ̀rọ isọ, kiyesi i,
Rebeka jade de, ẹniti a bí fun Betueli, ọmọ
Milka, aya Nahori, arakọnrin Abrahamu,
ti on ti ladugbo rẹ̀ li ejika rẹ̀.
16 Ọmọdan na li ẹwà gidigidi lati wò,
wundia ni, bẽli ẹnikẹni kò ti imọ̀ ọ : o si
sọkalẹ lọ sinu kanga, o si pọn ladugbo rẹ̀
kún, o si goke.
17 Iranṣẹ na si sure lọ ipade rẹ̀, o si
wipe, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki nmu omi diẹ ninu
ladugbo rẹ.
18 O si dahùn pe, Mu, oluwa mi : o si
yara, o sọ̀ ladugbo rẹ̀ ka ọwọ́, o si fun u mu.
19 Nigbati o si fun u mu tan, o si wipe,
Emi o pọn fun awọn ibakasiẹ rẹ pẹlu, titi
nwọn o fi mu tan.
20 O si yara, o si tú ladugbo rẹ̀ sinu
ibumu, o si tun pada sure lọ si kanga lati
pọn omi, o si pọn fun gbogbo awọn iba-
kasiẹ rẹ̀.
21 Ọkọnrin na si tẹjumọ ọ, o dakẹ, lati
mọ̀ bi OLUWA mu ìrin on dara, bi bẽkọ.
22 O si ṣe, bi awọn ibakasiẹ ti mu omi
tan, ni ọkọnrin na mu oruka wurà àbọ ìwọn
ṣekeli, ati jufù meji fun ọwọ́ rẹ̀, ti ìwọn ṣe-
keli wurà mẹwa ;
23 O si bi i pe, Ọmọbirin tani iwọ iṣe ?
Emi bẹ̀ ọ, wi fun mi : àye wà ni ile baba rẹ
fun wa lati wọ̀ si ?
24 On si wi fun u pe, Ọmọbirin Betueli,
ọmọ Milka, ti o bí fun Nahori, li emi iṣe.
25 O si wi fun u pe, Awa ni koriko ati
sakasáka tó pẹlu, ati àye lati wọ̀ si.
26 Ọkọnrin na si tẹriba, o si sìn OLUWA.
27 O si wipe, Olubukún li OLUWA,
Ọlọrun Abrahamu, oluwa mi, ti kò jẹ ki

Digitized by Google

ẹnu rẹ̀ ati otitọ rẹ̀ ki o yẹ̀ kuro lọdọ oluwa mi, niti emi, OLUWA fi ẹsẹ̀ mi le ọ̀na ile awọn arakọnrin baba mi.

28 Ọmọdan na si sure, o si rò nkan wọnyi fun awọn ara ile iya rẹ̀.

29 Rebeka si li arakọnrin kan, orukọ rẹ̀ si ni Labani: Labani si sure jade tọ̀ ọkọnrin na lọ si ibi kanga.

30 O si ṣe, bi o ti ri oruka, ati jufù li ọwọ́ arabirin rẹ̀, ti o si gbọ́ ọ̀rọ Rebeka arabirin rẹ̀ pe, Bayi li ọkọnrin na ba mi sọ; bẽli o si tọ̀ ọkọnrin na wá: si kiyesi i, o duro tì awọn ibakasiẹ rẹ̀ leti kanga na.

31 O si wipe, Wọle, iwọ ẹni-ibukún OLUWA; ẽṣe ti iwọ fi duro lode? mo sá ti pèse àye silẹ ati àye fun awọn ibakasiẹ.

32 Ọkọnrin na si wọle na wá: o si tú awọn ibakasiẹ, o si fun awọn ibakasiẹ ni koriko ati sakasáka, ati omi fun u lati wẹ̀ ẹsẹ̀ rẹ̀, ati ẹsẹ̀ awọn ọkọnrin ti o pẹlu rẹ̀.

33 A si gbé onjẹ kalẹ fun u lati jẹ: ṣugbọn on si wipe, Emi ki yio jẹun titi emi o fi jiṣẹ mi tán. On si wipe, Ma wi.

34 O si wipe, Ọmọ-ọdọ Abrahamu li emi iṣe.

35 OLUWA si ti bukún fun oluwa mi gidigidi; o si di pupọ̀: o si fun u li agutan, ati malu, ati fadaka, ati wurà, ati iranṣẹkọnrin, ati iranṣẹbirin, ati ibakasiẹ, ati kẹtẹkẹtẹ.

36 Sara, aya oluwa mi, si bí ọmọ kan fun oluwa mi nigbati on (Sara) gbó tán: on li o si fi ohun gbogbo ti o ni fun.

37 Oluwa mi si mu mi bura, wipe, Iwọ kò gbọdọ fẹ́ obirin fun ọmọ mi ninu awọn ọmọbirin ara Kenaani ni ilẹ ẹniti emi ngbé:

38 Bikoṣe ki iwọ ki o lọ si ile baba mi, ati si ọdọ awọn ibatan mi, ki o si fẹ́ aya fun ọmọ mi.

39 Emi si wi fun oluwa mi pe, Bọya obirin na ki yio tẹle mi.

40 O si wi fun mi pe, OLUWA, niwaju ẹniti emi nrìn, yio rán angeli rẹ̀ pẹlu rẹ, yio si mu ọ̀na rẹ dara; iwọ o si fẹ́ aya fun ọmọ mi lati ọdọ awọn ibatan mi, ati lati inu ile baba mi:

41 Nigbana li ọrùn rẹ yio mọ́ kuro ninu ibura mi yi, nigbati iwọ ba de ọdọ awọn ibatan mi; bi nwọn kò ba si fi ẹnikan fun ọ, ọrùn rẹ yio si mọ́ kuro ninu ibura mi.

42 Emi si de si ibi kanga loni, mo si wipe, OLUWA, Ọlọrun Abrahamu oluwa mi, bi iwọ ba mu ọ̀na àjo mi ti mo nlọ nisisiyi dara:

43 Kiyesi i, mo duro lẹba kanga omi; ki o si ṣẹ, pe nigbati wundia na ba jade wá ipọn omi, ti mo ba si wi fun u pe, Emi bẹ̀ ọ, bùn mi li omi diẹ ki emi mu lati inu ladugbo rẹ;

44 Ti o si wi fun mi pe, Iwọ mu, emi o si pọn fun awọn ibakasiẹ rẹ pẹlu: ki on na ki o ṣe obirin ti OLUWA ti yàn fun ọmọ oluwa mi.

45 Ki emi ki o si tó wi tán li ọkàn mi, kiyesi i, Rebeka jade de ti on ti ladugbo rẹ̀ li ejika rẹ̀; o si sọkalẹ lọ sinu kanga, o pọn omi: emi si wi fun u pe, Mo bẹ̀ ọ, jẹ ki emi mu omi.

46 O si yara, o si sọ ladugbo rẹ̀ kalẹ kuro li ejika rẹ̀, o si wipe, Mu, emi o si fi fun awọn ibakasiẹ mu pẹlu, bẽli emi mu, o si fi fun awọn ibakasiẹ mu pẹlu.

47 Emi si bi i, mo si wipe, Ọmọbirin tani iwọ iṣe? o si wipe, Ọmọbirin Betueli, ọmọ Nahori, ti Milka bí fun u; emi si fi oruka si i ni imu, ati jufù si ọwọ́ rẹ̀.

48 Emi si tẹriba, mo si wolẹ fun OLUWA, mo si fi ibukún fun OLUWA, Ọlọrun Abrahamu oluwa mi, ti o mu mi tọ̀ ọ̀na titọ lati mu ọmọbirin arakọnrin oluwa mi fun ọmọ rẹ̀ wá.

49 Njẹ nisisiyi, bi ẹnyin o ba bá oluwa mi lò inu rere ati otitọ, ẹ wi fun mi: bi bẽ si kọ; ẹ wi fun mi: ki emi ki o le pọ̀ si apa ọtún, tabi si òsi.

50 Nigbana ni Labani ati Betueli dahùn nwọn si wipe, Lọdọ OLUWA li ohun na ti jade wá: awa kò le sọ rere tabi buburu fun ọ.

51 Wò o, Rebeka niyi niwaju rẹ, mu u, ki o si ma lọ, ki on ki o si ma ṣe aya ọmọ oluwa rẹ, bi OLUWA ti wi.

52 O si ṣe, nigbati iranṣẹ Abrahamu gbọ́ ọ̀rọ wọn, o wolẹ fun OLUWA.

53 Iranṣẹ na si yọ ohun èlo fadaka, ati èlo wurà jade, ati aṣọ, o si fi wọn fun Rebeka: o si fi ohun iyebiye pẹlu fun arakọnrin rẹ̀ ati fun iya rẹ̀.

54 Nwọn si jẹ, nwọn si mu, on ati awọn ọkọnrin ti o wá pẹlu rẹ̀, nwọn si wọ̀ nibẹ̀ li oru ijọ́ na; nwọn si dide li owurọ̀, o si wipe, Ẹ rán mi lọ si ọdọ oluwa mi.

55 Arakọnrin ati iya rẹ̀ si wipe, Jẹ ki ọmọdan na ki o ba wa joko ni ijọ́ melokan, bi ijọ́ mẹwa, lẹhin eyini ni ki o ma wa lọ.

56 On si wi fun wọn pe, Ẹ máse da mi duro, OLUWA sa ti ṣe ọ̀na mi ni rere; ẹ rán mi, ki emi ki o le tọ̀ oluwa mi lọ.

57 Nwọn si wipe, Awa o pè ọmọdan na, a o si bère li ẹnu rẹ̀.

58 Nwọn si pè Rebeka, nwọn bi i pe,

Digitized by Google

Iwọ o bá ọkọnrin yi lọ? o si wipe, Emi
o lọ.
59 Nwọn si rán Rebeka, arabirin wọn,
ati olutọ rẹ̀, ati iranṣẹ Abrahamu, ati awọn
ọkọnrin rẹ̀ lọ.
60 Nwọn si sure fun Rebeka, nwọn si
wi fun u pe, Iwọ li arabirin wa, ki iwọ ki
o si ṣe iya ẹgbẹgbẹrun lọnà ẹgbārun, ki
irú-ọmọ rẹ ki o si ni ẹnubode awọn ti o
korira wọn.
61 Rebeka si dide, ati awọn ọmọdan rẹ̀,
nwọn si gùn awọn ibakasiẹ, nwọn si tẹle
ọkọnrin na: iranṣẹ na si mu Rebeka o si
ba tirẹ̀ lọ.
62 Isaaki si nti ọ̀na kanga Lahai-roi
mbọ̀wá; nitori ilu ìha gusù li on ngbé.
63 Isaaki si jade lọ ṣe àṣaro li oko li
aṣalẹ: o si gbé oju rẹ̀ soke, o si ri i, si
kiyesi i, awọn ibakasiẹ mbọ̀wá.
64 Rebeka si gbé oju rẹ̀ soke, nigbati o
ri Isaaki, o sọkalẹ lori ibakasiẹ.
65 Nitori ti o ti bi iranṣẹ na pe, Ọkọnrin
wo li o nrìn bọ̀ li-oko lati wá kò wa
nì? Iranṣẹ na si ti wi fun u pe, oluwa
mi ni: nitori na li o ṣe mu iboju o fi bò
ara rẹ̀.
66 Iranṣẹ na si rò ohun gbogbo ti on ṣe
fun Isaaki.
67 Isaaki si mu u wá si inu agọ́ Sara,
iya rẹ̀, o si mu Rebeka, o di aya rẹ̀; o si
fẹ́ ẹ; a si tu Isaaki ninu lẹhin ikú iya rẹ̀.

## ORI 25.

ABRAHAMU si tun fẹ́ aya kan, orukọ rẹ̀
a ma jẹ Ketura.
2 O si bí Simrani, ati Jokṣani, ati Me-
dani, ati Midiani, ati Iṣbaku, ati Ṣua
fun u.
3 Jokṣani si bí Ṣeba, ati Dedani. Awọn
ọmọ Dedani si ni Aṣurimu, ati Letuṣimu,
ati Leumimu.
4 Ati awọn ọmọ Midiani; Efa, ati Eferi,
ati Hanoku, ati Abida, ati Eldaa. Gbo-
gbo awọn wọnyi li ọmọ Ketura.
5 Abrahamu si fi gbogbo ohun ti o ni
fun Isaaki.
6 Ṣugbọn awọn ọmọ àle ti Abrahamu ni,
Abrahamu bùn wọn li ẹ̀bun, o si rán wọn
lọ kuro lọdọ Isaaki, ọmọ rẹ̀, nigbati o wà
lāye, si ìha ìla-õrùn, si ilẹ ìla-õrùn.
7 Wọnyi si li ọjọ́ ọdún aiye Abrahamu
ti o wà, arundílọgọsan ọdún.
8 Abrahamu si jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ, o si
kú li ogbologbo, arugbo, o kún fun ọjọ́; a
si kó o jọ pẹlu awọn enia rẹ̀.
9 Awọn ọmọ rẹ̀, Isaaki ati Iṣmaeli si
sin i ni ihò Makpela, li oko Efroni, ọmọ
Sohari enia Hitti, ti o wà niwaju Mamre;
10 Oko ti Abrahamu rà lọwọ awọn ọmọ
Heti: nibẹ̀ li a gbé sin Abrahamu, ati
Sara, aya rẹ̀.
11 O si ṣe lẹhin ikú Abrahamu li Ọlọrun
bukún u fun Isaaki, ọmọ rẹ̀; Isaaki si joko
leti kanga Lahai-roi.
12 Wọnyi si ni iran Iṣmaeli, ọmọ Abra-
hamu, ti Hagari, ara Egipti, ọmọbirin ọdọ
Sara bí fun Abrahamu:
13 Wọnyi si li orukọ awọn ọmọkọnrin
Iṣmaeli, nipa orukọ wọn, ni iran idile wọn:
akọ́bi Iṣmaeli, Nebajotu; ati Kedari, ati
Adbeeli, ati Mibsamu,
14 Ati Miṣma, ati Duma, ati Masa;
15 Hadari, ati Tema, Jeturi, Nafiṣi, ati
Kedema:
16 Awọn wọnyi li awọn ọmọ Iṣmaeli,
wọnyi si li orukọ wọn, li ori-ori ilu wọn,
li ori-ori ile odi wọn; ijoye mejila li orilẹ-
ède wọn.
17 Wọnyi si li ọdún aiye Iṣmaeli, ẹta-
dilogoje ọdún: o si jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ, o si
kú; a si kó o jọ pọ̀ pẹlu awọn enia rẹ̀.
18 Nwọn si tẹ̀dó lati Hafila lọ titi o fi
de Ṣuri, ti o wà niwaju Egipti, bi iwọ ti
nlọ sìha Assiria: o si kú niwaju awọn ara-
kọnrin rẹ̀ gbogbo.
19 Wọnyi si ni iran Isaaki, ọmọ Abra-
hamu: Abrahamu bí Isaaki:
20 Isaaki si jẹ ẹni ogoji ọdún, nigbati o
mu Rebeka, ọmọbirin Betueli, ara Siria ti
Padan-aramu, arabirin Labani ara Siria, li
aya.
21 Isaaki si bẹ̀ OLUWA fun aya rẹ̀, nito-
riti o yàgan: OLUWA si gbà ẹ̀bẹ rẹ̀, Re-
beka, aya rẹ̀, si loyun.
22 Awọn ọmọ si njàgudu ninu rẹ̀: o si
wipe, bi o ba ṣe pe bẽni yio ri, ẽse ti mo fi
ri bayi? O si lọ bère lọdọ OLUWA.
23 OLUWA si wi fun u pe, orilẹ-ède meji
ni mbẹ ninu rẹ, irú enia meji ni yio yà lati
inu rẹ: awọn enia kan yio le jù ekeji lọ;
ẹgbọ́n ni yio si ma sìn aburo.
24 Nigbati ọjọ́ rẹ̀ ti yio bí si pé, si kiye-
si i, ibeji li o wà ninu rẹ̀.
25 Akọ́bi si jade wá, o pupa, ara rẹ̀ gbo-
gbo ri bí aṣọ onirùn; nwọn si sọ orukọ rẹ̀
ni Esau.
26 Ati lẹhin eyini li arakọnrin rẹ̀ jade
wá, ọwọ́ rẹ̀ si dì gigĩsẹ Esau mu; a si sọ
orukọ rẹ̀ ni Jakobu: Isaaki si jẹ ẹni ọgọta
ọdún nigbati Rebeka bí wọn.
27 Awọn ọmọdekọnrin na si dàgba:

Digitized by Google

Esau si ṣe ọlọgbọ́n ọdẹ, ara oko; Jakobu si jẹ ọbọrọ́ enia, a ma gbé inu agọ́.

28 Isaaki si fẹ́ Esau, nitori ti o njẹ ninu ẹran-ọdẹ rẹ̀: ṣugbọn Rebeka fẹ́ Jakobu.

29 Jakobu si pa ìpẹtẹ: Esau si ti inu igbẹ́ dé, o si rẹ̀ ẹ:

30 Esau si wi fun Jakobu pe, Emi bẹ̀ ọ, fi ìpẹtẹ rẹ pupa nì bọ́ mi; nitori ti o rẹ̀ mi: nitori na li a ṣe npè orukọ rẹ̀ ni Edomu.

31 Jakobu si wipe, Tà ogún-ibí rẹ fun mi loni.

32 Esau si wipe, Sa wò o na, emi ni nkú lọ yi: ore kini ogún-ibí yi yio si ṣe fun mi?

33 Jakobu si wipe, Bura fun mi loni; o si bura fun u: o si tà ogún-ibí rẹ̀ fun Jakobu.

34 Nigbana ni Jakobu fi àkara ati ìpẹtẹ lentile fun Esau; o si jẹ, o si mu, o si dide, o si ba tirẹ̀ lọ: bayi ni Esau gàn ogún-ibí rẹ̀.

## ORI 26.

ÌYAN kan si mu ni ilẹ na, lẹhin ìyan ti o tetekọ mu li ọjọ́ Abrahamu. Isaaki si tọ̀ Abimeleki, ọba awọn ara Filistia lọ, si Gerari.

2 OLUWA si farahàn a, o si wipe, Máṣe sọkalẹ lọ si Egipti; joko ni ilẹ ti emi o wi fun ọ.

3 Mã ṣe atipo ni ilẹ yi, emi o si pẹlu rẹ, emi o si bukún u fun ọ; nitori iwọ ati irú-ọmọ rẹ, li emi o fi gbogbo ilẹ wọnyi fun, emi o si mu ara ti mo bú fun Abrahamu, baba rẹ, ṣẹ.

4 Emi o si mu irú-ọmọ rẹ bisi i bi irawọ oju-ọrun, emi o si fi gbogbo ilẹ wọnyi fun irú-ọmọ rẹ; ati nipasẹ irú-ọmọ rẹ li a o bukún gbogbo orilẹ-ède aiye;

5 Nitoriti Abrahamu gbà ohùn mi gbọ́, o si pa ìlọ mi, ìlana mi, ati ofin mi mọ́.

6 Isaaki si joko ni Gerari.

7 Awọn ọkọnrin ibẹ̀ na bi i lẽre niti aya rẹ̀: o si wipe, Arabirin mi ni: nitoriti o bẹ̀ru ati wipe, Aya mi ni; o ni, ki awọn ọkọnrin ibẹ̀ na ki o má ba pa mi nitori Rebeka; nitoriti on li ẹwà lati wò.

8 O si ṣe nigbati o joko nibẹ̀ pẹ titi, ni Abimeleki, ọba awọn ara Filistia, wò ode li ojuferese, o si ri, si kiyesi i, Isaaki mba Rebeka aya rẹ̀ wẹ́.

9 Abimeleki si pè Isaaki, o si wipe, Kiyesi i, nitõtọ aya rẹ ni iṣe: iwọ ha ti ṣe wipe, Arabirin mi ni? Isaaki si wi fun u pe, Nitoriti mo wipe, ki emi ki o má ba kú nitori rẹ̀.

10 Abimeleki si wipe Kili eyiti iwọ ṣe si wa yi? ọkan ninu awọn enia iba lọ iba aya rẹ ṣe iṣekuṣe nkọ́? iwọ iba si mu ẹṣẹ wa si ori wa.

11 Abimeleki si kìlọ fun gbogbo awọn enia rẹ̀ wipe, Ẹnikẹni ti o ba tọ́ ọkọnrin yi tabi aya rẹ̀, kikú ni yio kú.

12 Nigbana ni Isaaki funrugbìn ni ilẹ na, o si ri ọrọrún mu li ọdún na; OLUWA si busi i fun u:

13 Ọkọnrin na si di pupọ̀, o si nlọ si iwaju, o si npọ̀ si i titi o fi di enia nla gidigidi.

14 Nitori ti o ni agbo-agutan, ati ini agbo-ẹran nla ati ọ̀pọlọpọ ọmọ-ọdọ: awọn ara Filistia si ṣe ilara rẹ̀.

15 Nitori gbogbo kanga ti awọn ọmọ-ọdọ baba rẹ̀ ti wà li ọjọ́ Abrahamu, baba rẹ̀, awọn ara Filistia dí wọn, nwọn si fi erupẹ dí wọn.

16 Abimeleki si wi fun Isaaki pe, Lọ kuro lọdọ wa; nitori ti iwọ lagbara pupọ̀ ju wa lọ.

17 Isaaki si ṣí kuro nibẹ̀, o si pa agọ́ rẹ̀ ni afonifoji Gerari, o si joko nibẹ̀.

18 Isaaki si tun wà kanga omi, ti nwọn ti wà li ọjọ́ Abrahamu, baba rẹ̀; nitori ti awọn ara Filistia ti dí wọn lẹhin ikú Abrahamu: o si pè orukọ wọn gẹgẹ bi orukọ ti baba rẹ̀ sọ wọn.

19 Awọn ọmọ-ọdọ Isaaki si wàlẹ li afonifoji nì, nwọn si kàn kanga isun omi nibẹ̀.

20 Awọn darandaran Gerari si mba awọn darandaran Isaaki jà, wipe, Ti wa li omi na: o si sọ orukọ kanga na ni Eseki; nitori ti nwọn bá a jà.

21 Nwọn si tun wà kanga miran, nwọn si tun jà nitori eyi na pẹlu: o si sọ orukọ rẹ̀ ni Sitna.

22 O si ṣí kuro nibẹ̀, o si wà kanga miran: nwọn kò si jà nitori rẹ̀: o si pè orukọ re ni Rehoboti; o si wipe, Njẹ nigbayi li OLUWA tó fi àye fun wa, awa o si ma bisi i ni ilọ yi.

23 O si goke lati ibẹ̀ lọ si Beerṣeba.

24 OLUWA si farahàn a li oru ọjọ́ na, o si wipe, Emi li Ọlọrun Abrahamu, baba rẹ: máṣe bẹ̀ru, nitori ti emi wà pẹlu rẹ, emi o si busi i fun ọ, emi o si mu irú-ọmọ rẹ rẹ̀, nitori Abrahamu ọmọ-ọdọ mi.

25 O si tẹ́ pẹpẹ kan nibẹ̀, o si kepè orukọ OLUWA, o si pa agọ́ rẹ̀ nibẹ̀: awọn ọmọ-ọdọ Isaaki si wà kanga kan nibẹ̀.

26 Nigbana li Abimeleki tọ̀ ọ lati Gerari

Digitized by Google

lọ, ati Ahusati, ọkan ninu awọn ọ̀rẹ́ rẹ̀, ati
Fikoli, olori ogun rẹ̀.
27 Isaaki si bi wọn pe, Nitori kili ẹnyin
ṣe tọ̀ mi wá, ẹnyin sa korira mi, ẹnyin si ti
lé mi kuro lọdọ nyin?
28 Nwọn si wipe, Awa ri i nitõtọ pe,
OLUWA wà pẹlu rẹ: awa si wipe, Njẹ nisi-
siyi jẹ ki ibura ki o wà lãrin wa, ani lãrin
tawa tirẹ, ki awa ki o si ba iwọ dá majẹmu;
29 Pe iwọ ki yio ṣe wa ni ibi, bi awa kò
si ti fọwọkàn ọ, ati bi awa kò si ti ṣe ọ ni
nkan bikoṣe rere, ti awa si rán ọ jade li
alafia: nisisiyi ẹni-ibukún OLUWA ni iwọ.
30 O si sè àse fun wọn, nwọn si jẹ, nwọn
si mu.
31 Nwọn si dide ni kutukutu owurọ̀,
nwọn si bura fun ara wọn: Isaaki si rán
wọn pada lọ, nwọn si lọ kuro lọdọ rẹ̀ li
alafia.
32 O si ṣe ọjọ́ kanna li awọn ọmọ-ọdọ
Isaaki wá, nwọn si rò fun u niti kanga ti
nwọn wà, nwọn si wi fun u pe, Awa kàn
omi.
33 O sọ orukọ rẹ̀ ni Ṣeba: nitorina li
orukọ ilu na ṣe njẹ Beer-ṣeba titi di oni.
34 Esau si di ẹni ogoji ọdún nigbati o
mu Juditi li aya, ọmọbirin Beeri, ara Hitti,
ati Baṣemati, ọmọbirin Eloni, ara Hitti:
35 Ohun ti o ṣe ibinujẹ fun Isaaki ati
fun Rebeka.

## ORI 27.

O SI ṣe, ti Isaaki gbó, ti oju rẹ̀ si nṣe
bàibai, tobẽ ti kò le riran, o pè Esau,
ọmọ rẹ̀ akọ́bi, o si wi fun u pe, Ọmọ mi:
on si dá a li ohùn pe, Emi niyi.
2 O si wipe, Wò o na, emi di arugbo,
emi kò si mọ̀ ọjọ́ ikú mi;
3 Njẹ nisisiyi, emi bẹ̀ ọ, mu ohun ọdẹ
rẹ, apó rẹ, ati ọrun rẹ, ki o si jade lọ si
igbẹ́ ki o si pa ẹran-igbẹ́ fun mi wá:
4 Ki o si sè ẹran adidùn fun mi, bi irú
eyiti mo fẹ́, ki o si gbé e tọ̀ mi wa, ki emi
ki o jẹ: ki ọkàn mi ki o sure fun ọ ki emi
to kú.
5 Rebeka si gbọ́ nigbati Isaaki nwi fun
Esau, ọmọ rẹ̀. Esau si lọ si igbẹ́ lọ iṣọdẹ,
lati pa ẹran-igbẹ́ wá.
6 Rebeka si wi fun Jakobu ọmọ rẹ̀ pe,
Wò o, mo gbọ́ baba rẹ wi fun Esau arakọn-
rin rẹ pe,
7 Mu ẹran-igbẹ́ fun mi wá, ki o si sè
ẹran adidùn fun mi, ki emi ki o jẹ ki emi
ki o sure fun ọ niwaju OLUWA ṣaju ikú mi.
8 Njẹ nisisiyi, ọmọ mi gbọ́ ohùn mi,
gẹgẹ bi emi o ti paṣẹ fun ọ.
9 Lọ nisisiyi sinu agbo-ẹran, ki o si mu
ọmọ ewurẹ meji daradara fun mi lati ibẹ̀
wá: emi o si sè wọn li ẹran adidùn fun
baba rẹ, bi irú eyiti o fẹ́:
10 Iwọ o si gbé e tọ̀ baba rẹ lọ, ki o le
jẹ, ki o le sure fun ọ, ki on to kú.
11 Jakobu si wi fun Rebeka iya rẹ̀ pe,
Kiyesi i, enia onirun ni Esau arakọnrin mi,
alara ọbọrọ́ si li emi:
12 Bọya baba mi yio fọwọbà mi, emi o si
dabi ẹlẹ̀tan fun u; emi o si mu egún wá si
ori mi ki yio ṣe ibukún.
13 Iya rẹ̀ si wi fun u pe, lori mi ni ki
egún rẹ wà, ọmọ mi: sá gbọ́ ohùn mi, ki o
si lọ mu wọn fun mi wá.
14 O si lọ, o mu wọn, o si fà wọn tọ̀ iya
rẹ̀ wá: iya rẹ̀ si sè ẹran adidùn; bi irú
eyiti baba rẹ̀ fẹ́.
15 Rebeka si mu ãyo aṣọ Esau, ọmọ rẹ̀
ẹgbọ́n, ti o wà lọdọ rẹ̀ ni ile, o si fi wọn wọ̀
Jakobu, ọmọ rẹ̀ aburo:
16 O si fi awọ awọn ọmọ ewurẹ wọnni bò
o li ọwọ́, ati si ọbọrọ́ ọrùn rẹ̀:
17 O si fi ẹran adidùn na, ati àkara ti o
ti pèse, le Jakobu, ọmọ rẹ̀, lọwọ.
18 O si tọ̀ baba rẹ̀ wá, o wipe, Baba mi:
on si wipe, Emi niyi; iwọ tani nì ọmọ mi?
19 Jakobu si wi fun baba rẹ̀ pe, Emi
Esau akọ́bi rẹ ni; emi ti ṣe gẹgẹ bi o ti sọ
fun mi, dide joko, emi bẹ̀ ọ, ki o si jẹ ninu
ẹran-igbẹ́ mi, ki ọkàn rẹ le sure fun mi.
20 Isaaki si wi fun ọmọ rẹ̀ pe, Ẽti ri ti
iwọ fi tete ri i bẽ, ọmọ mi? on si wipe, Ni-
toriti OLUWA Ọlọrun rẹ mu u tọ̀ mi wá ni.
21 Isaaki si wi fun Jakobu pe, Emi bẹ̀
ọ, sunmọ mi, ki emi ki o fọwọbà ọ, ọmọ
mi, bi iwọ iṣe Esau, ọmọ mi nitotọ, bi
bẽkọ.
22 Jakobu si sunmọ Isaaki baba rẹ̀, o si
fọwọbà a, o si wipe, Ohùn Jakobu li ohùn,
ṣugbọn ọwọ́ li ọwọ́ Esau.
23 On kò si mọ̀ ọ, nitoriti ọwọ́ rẹ̀ ṣe
onirun, bi ọwọ́ Esau, arakọnrin rẹ̀: bẽli o
sure fun u.
24 O si wipe, Iwọ ni Esau ọmọ mi nito-
tọ? o si wipe, emi ni.
25 O si wipe, Gbé e sunmọ ọdọ mi, emi
o si jẹ ninu ẹran-igbẹ́ ọmọ mi, ki ọkàn mi
ki o le sure fun ọ. O si gbé e sunmọ ọdọ
rẹ̀, o si jẹ: o si gbé ọti-waini fun u, on
si mu.
26 Isaaki baba rẹ̀ si wi fun u pe, Sunmọ
ihín nisisiyi ọmọ mi, ki o si fi ẹnu kò mi
li ẹnu.
27 O si sunmọ ọ, o si fi ẹnu kò o li ẹnu:
o si gbọ́ õrùn aṣọ rẹ̀, o si sure fun u, o si

Digitized by Google

wipe, Wò o, õrùn ọmọ mi o dabi õrùn oko
eyiti Oluwa ti busi.
28 Ọlọrun yio si fun ọ ninu ìri ọrun, ati
ninu ọrá ilẹ, ati ọ́pọlọpọ ọkà ati ọti-waini:
29 Ki enia ki o mã sìn ọ, ki orilẹ-ède ki
o mã tẹriba fun ọ: mã ṣe oluwa awọn ara-
kọnrin rẹ, ki awọn ọmọ iya rẹ ki o tẹriba
fun ọ: ifibú li awọn ẹniti o fi ọ bú, ibukún
si ni fun awọn ẹniti o sure fun ọ.
30 O si ṣe, bi Isaaki ti pari ire isú fun
Jakobu, ti Jakobu si fẹrẹ má jade tan kuro
niwaju Isaaki baba rẹ̀, ni Esau, arakọnrin
rẹ̀ wọle de lati igbẹ́ ọdẹ rẹ̀ wá.
31 On pẹlu si ti sè ẹran adidùn, o si mu
u tọ̀ baba rẹ̀ wá, o si wi fun baba rẹ̀ pe, Ki
baba mi ki o dide ki o si jẹ ninu ẹran-igbẹ́
ọmọ rẹ̀, ki ọkàn rẹ le sure fun mi.
32 Isaaki baba rẹ̀ si bi i pe, Iwọ tani nì?
on si wipe, Emi Esau, ọmọ rẹ akọbi ni.
33 Isaaki si warìri gidigidi rekọja, o si
wipe, Tani nla? tali ẹniti o ti pa ẹran-igbẹ́,
ti o si gbé e tọ̀ mi wá, emi si ti jẹ ninu
gbogbo rẹ̀, ki iwọ ki o to de, emi si ti sure
fun u? nitõtọ a o si bukún fun u.
34 Nigbati Esau gbọ́ ọ̀rọ baba rẹ̀, o fi
igbe nlanla ta, o si sun ẹkun kikorò gidi-
gidi, o si wi fun baba rẹ̀ pe, Sure fun mi,
ani fun emi pẹlu, baba mi.
35 O si wipe, Arakọnrin rẹ fi erú wá, o
si ti gbà ibukún rẹ lọ.
36 O si wipe, A kò ha pè orukọ rẹ̀ ni
Jakobu ndan? nitori o jì mi li ẹsẹ̀ ni ìgba
meji yi: o gbà ogún-ibi lọwọ mi; si kiyesi
i, nisisiyi o si gbà ire mi lọ. O si wipe,
Iwọ kò ha pa ire kan mọ́ fun mi?
37 Isaaki si dahùn o si wi fun Esau pe,
Wõ, emi ti fi on ṣe oluwa rẹ, ati gbogbo
awọn arakọnrin rẹ̀ li emi ti fi ṣe iranṣẹ rẹ̀;
ati ọkà ati ọti-waini ni mo fi gbè e: ewo li
emi o ha ṣe fun ọ nisisiyi ọmọ mi?
38 Esau si wi fun baba rẹ̀ pe, Ire kanṣoṣo
li o ni iwọ baba mi? sure fun mi, ani fun
mi pẹlu, baba mi? Esau si gbé ohùn rẹ̀
soke, o sọkun.
39 Isaaki baba rẹ̀ si dahùn o si wi fun u
pe, Wõ, ibujoko rẹ yio jẹ ọrá ilẹ, ati ibi ìri
ọrun lati oke wá;
40 Nipa idà rẹ ni iwọ o ma gbé, iwọ o si
ma sìn arakọnrin rẹ; yio si ṣe nigbati iwọ
ba di alagbara tan, iwọ o já àjaga rẹ̀ kuro
li ọrùn rẹ.
41 Esau si korira Jakobu nitori ire ti
baba rẹ̀ su fun u: Esau si wi li ọkàn rẹ̀ pe,
Ọjọ́ ọ̀fọ baba mi sunmọ-etile; nigbana li
emi o pa Jakobu, arakọnrin mi.
42 A si sọ ọ̀rọ Esau akọ́bi rẹ̀ wọnyi fun
Rebeka: on si ranṣẹ o si pè Jakobu, ọmọ
rẹ̀ aburo, o si wi fun u pe, Kiyesi i, Esau,
arakọnrin rẹ, ntù ara rẹ̀ ninu niti rẹ lati
pa ọ.
43 Njẹ nisisiyi ọmọ mi, gbọ́ ohùn mi;
si dide, sá tọ̀ Labani arakọnrin mi lọ si
Harani;
44 Ki o si bá a joko ni ijọ́ melo kan, titi
ibinu arakọnrin rẹ yio fi tuka;
45 Titi inu arakọnrin rẹ yio fi tutu si ọ,
ti yio si fi gbagbe ohun ti o fi ṣe e: ni-
gbana li emi o ranṣẹ mu ọ lati ibẹ̀ wá:
ẽṣe ti emi o fi fẹ́ ẹnyin mejeji kù ni ijọ́
kanṣoṣo?
46 Rebeka si wi fun Isaaki pe, Agara
aiye mi ma dá mi nitori awọn ọmọbirin
Heti, bi Jakobu ba fẹ́ aya ninu awọn ọmọ-
birin Heti, bi irú awọn wọnyi ti iṣe ninu
awọn ọmọbirin ilẹ yi, aiye mi o ha ti ri?

## ORI 28.

ISAAKI si pè Jakobu, o si sure fun u, o
si kìlọ fun u, o si wi fun u pe, Iwọ kò
gbọdọ fẹ́ aya ninu awọn ọmọbirin Kenaani.
2 Dide, lọ si Padan-aramu, si ile Betueli,
baba iya rẹ; ki iwọ ki o si fẹ́ aya lati ibẹ̀
wá ninu awọn ọmọbirin Labani, arakọnrin
iya rẹ.
3 Ki Ọlọrun Olodumare ki o gbẹ̀ ọ, ki o
si mu ọ bisi i, ki o si mu ọ rẹ̀ si i, ki iwọ
ki o le di ọ̀pọlọpọ enia.
4 Ki o si fi ibukún Abrahamu fun ọ, fun
iwọ ati fun irú-ọmọ rẹ pẹlu rẹ; ki iwọ ki o
le ni ilẹ na ninu eyiti iwọ nṣe atipo, ti
Ọlọrun fi fun Abrahamu.
5 Isaaki si rán Jakobu lọ: o si lọ si
Padan-aramu si ọdọ Labani ọmọ Betueli,
ara Siria, arakọnrin Rebeka, iya Jakobu on
Esau.
6 Nigbati Esau ri pe Isaaki sure fun
Jakobu ti o si rán a lọ si Padan-aramu, lati
fẹ́ aya lati ibẹ̀; ati pe bi o ti sure fun u, o
si kìlọ fun u wipe, iwọ kò gbọdọ fẹ́ aya ninu
awọn ọmọbirin Kenaani;
7 Ati pe Jakobu gbọ́ ti baba ati ti iya
rẹ̀, ti o si lọ si Padan-aramu:
8 Nigbati Esau ri pe awọn ọmọbirin Ke-
naani kò wù Isaaki baba rẹ̀;
9 Nigbana ni Esau tọ̀ Iṣmaeli lọ, o si fẹ́
Mahalati ọmọbirin Iṣmaeli, ọmọ Abrahamu,
arabirin Nebajotu, kún awọn obirin ti o ni.
10 Jakobu si jade kuro lati Beer-ṣeba lọ,
o si lọ si ìha Harani.
11 O si de ibi kan, o duro nibẹ̀ li oru na,
nitori õrùn wọ̀; o si mu ninu okuta ibẹ̀ na,
o fi ṣe irọri rẹ̀, o si sùn nibẹ̀ na.

Digitized by Google

12 O si lá alá, si kiyesi i, a gbé àkasọ kan duro lori ilẹ, ori rẹ̀ si de oke ọrun: si kiyesi i, awọn angeli Ọlọrun ngoke, nwọn si nsọkalẹ lori rẹ̀.

13 Si kiyesi i, OLUWA duro loke rẹ̀, o si wi pe, Emi li OLUWA, Ọlọrun Abrahamu baba rẹ, ati Ọlọrun Isaaki; ilẹ ti iwọ dubulẹ le nì, iwọ li emi o fi fun, ati fun irú-ọmọ rẹ.

14 Irú-ọmọ rẹ yio si ri bi erupẹ̀ ilẹ, iwọ o si tàn kalẹ si ìha ìwọ-õrùn, ati si ìha ìla-õrùn, ati si ìha ariwa, ati si ìha gusù: ninu rẹ, ati ninu irú-ọmọ rẹ li a o bukún fun gbogbo ibatan aiye.

15 Si kiyesi i, emi wà pẹlu rẹ, emi o si pa ọ mọ́ ni ibi gbogbo ti iwọ nlọ, emi o si tun mu ọ bọ̀wá si ilẹ yi; nitori emi ki yio kọ̀ ọ silẹ, titi emi o fi ṣe eyiti mo wi fun ọ tan.

16 Jakobu si jí li oju-orun rẹ̀, o si wipe, OLUWA mbẹ nihinyi nitõtọ; emi kò si mọ̀.

17 Ẹrù si bà a, o si wipe, Ihinbayi ti li ẹ̀ru tó! eyi ki iṣe ibi omiran, bikoṣe ile Ọlọrun, eyi si li ẹnubode ọrun.

18 Jakobu si dide ni kutukutu owurọ̀, o si mu okuta ti o fi ṣe irọri rẹ̀, o si fi lelẹ fun ọwọ̀n o si ta oróro si ori rẹ̀.

19 O si pè orukọ ibẹ̀ na ni Beteli: ṣugbọn Lusi li orukọ ilu na ri.

20 Jakobu si jẹ́ ẹjẹ́ wipe, Bi Ọlọrun ba pẹlu mi, ti o si pa mi mọ́ li ọ̀na yi ti emi ntọ̀, ti o si fun mi li ohun jijẹ, ati aṣọ bibora,

21 Ti mo si pada wá si ile baba mi li alafia; njẹ OLUWA ni yio ma ṣe Ọlọrun mi.

22 Okuta yi, ti mo fi lelẹ ṣe ọwọ̀n ni yio si ṣe ile Ọlọrun: ati ninu ohun gbogbo ti iwọ o fi fun mi, emi o si fi idamẹwa rẹ̀ fun ọ.

## ORI 29.

JAKOBU si mu ọ̀na àjo rẹ̀ pọn, o si wá si ilẹ awọn ara ìla-õrùn.

2 O si wọ̀, si kiyesi i, kanga kan ninu oko, si kiyesi i, agbo-agutan mẹta dubulẹ tì i; nitori pe, lati inu kanga na wá ni nwọn ti nfi omi fun awọn agbo-agutan: okuta nla si wà li ẹnu kanga na.

3 Nibẹ̀ ni gbogbo awọn agbo-ẹran kojọ pọ̀ si: nwọn si yí okuta na kuro li ẹnu kanga, nwọn si fun awọn agutan li omi, nwọn si tun yí okuta dí ẹnu kanga si ipò rẹ̀.

4 Jakobu si bi wọn pe, Ẹnyin arakọnrin mi, nibo li ẹnyin ti wá? nwọn si wipe, lati Harani li a ti wá.

5 O si bi wọn pe, ẹnyin mọ̀ Labani, ọmọ Nahori? Nwọn si wipe, Awa mọ̀ ọ.

6 O si bi wọn pe, Alafia ki o wà bi? nwọn si wipe Alafia ni; si kiyesi i, Rakeli, ọmọbirin rẹ̀ mbọ̀wá pẹlu ọwọ-ẹran.

7 O si wipe, Kiyesi i, ọjọ́ mbẹ sibẹ̀, bẽni kò tó akokò ti awọn ẹran yio wọjọ pọ̀: ẹ fun awọn agutan li omi, ki ẹ si lọ ibọ́ wọn.

8 Nwọn si wipe, Awa kò le ṣe e, titi gbogbo awọn agbo-ẹran yio fi wọjọ pọ̀, ti nwọn o si fi yí okuta kuro li ẹnu kanga; nigbana li a le fun awọn agutan li omi.

9 Nigbati o si mba wọn sọ̀rọ lọwọ, Rakeli de pẹlu awọn agutan baba rẹ̀: on li o sa nṣọ́ wọn.

10 O si ṣe, nigbati Jakobu ri Rakeli, ọmọbirin Labani, arakọnrin iya rẹ̀, ati agutan Labani, arakọnrin iya rẹ̀, ni Jakobu si sunmọ ibẹ̀, o si yí okuta kuro li ẹnu kanga, o si fi omi fun gbogbo agbo-ẹran Labani, arakọnrin iya rẹ̀.

11 Jakobu si fi ẹnu kò Rakeli li ẹnu, o si gbé ohùn rẹ̀ soke, o sọkun.

12 Jakobu si wi fun Rakeli pe arakọnrin baba rẹ̀ li on, ati pe, ọmọ Rebeka li on: ọmọbirin na si sure o si sọ fun baba rẹ̀.

13 O si ṣe ti Labani gburó Jakobu, ọmọ arabirin rẹ̀, o sure lọ ipade rẹ̀, o si gbá a mú, o si fi ẹnu kò o li ẹnu, o si mu u wá si ile rẹ̀. On si ròhin gbogbo nkan wọnni fun Labani.

14 Labani si wi fun u pe, egungun on ẹran-ara mi ni iwọ iṣe nitõtọ. O si bá a joko ni ìwọn oṣù kan.

15 Labani si wi fun Jakobu pe, Iwọ o ha ma sìn mi li asan bi. nitoriti iwọ iṣe arakọnrin mi? elo li owo iṣẹ rẹ, wi fun mi?

16 Labani si ni ọmọbirin meji: orukọ ẹgbọ́n a ma jẹ Lea, orukọ aburo a si ma jẹ Rakeli.

17 Oju Lea kò li ẹwà, ṣugbọn Rakeli ṣe arẹwà, o si wù ni.

18 Jakobu si fẹ́ Rakeli; o si wipe, Emi o sìn ọ li ọdún meje nitori Rakeli, ọmọbirin rẹ abikẹhin.

19 Labani si wipe, O san lati fi i fun ọ, jù ki nfi i fun ẹlomiran lọ: ba mi joko.

20 Jakobu si sìn i li ọdún meje fun Rakeli; nwọn sì dabi ijọ́ melokan li oju rẹ̀ nitori ifẹ́ ti o fẹ́ ẹ.

21 Jakobu si wi fun Labani pe, Fi aya mi fun mi, nitoriti ọjọ́ mi pé, ki emi ki o le wọle tọ̀ ọ.

22 Labani si pè gbogbo awọn enia ibẹ̀ jọ, o si se àse.

Digitized by Google

23 O si ṣe li alẹ, o mú Lea ọmọbirin rẹ̀, o sìn i tọ̀ ọ wá; on si wọle tọ̀ ọ lọ.

24 Labani si fi Silpa, ọmọ-ọdọ rẹ̀, fun Lea, ọmọbirin rẹ̀, ni iranṣẹ rẹ̀.

25 O si ṣe, li owurọ, wò o, o jẹ́ Lea: o si wi fun Labani pe, Ewo li eyiti iwọ ṣe si mi yi? nitori Rakeli ki mo ṣe sìn ọ, njẹ ẽhatiṣe ti o fi ṣe erú si mi?

26 Labani si wi fun u pe, A kò gbọdọ ṣe bẽni ilẹ wa, lati sìn aburo ṣaju ẹgbọ́n.

27 Ṣe ọ̀sẹ ti eleyi pé, awa o si fi eyi fun ọ pẹlu, nitori ìsin ti iwọ o sìn mi li ọdún meje miran si i.

28 Jakobu si ṣe bẽ, o si ṣe ọ̀sẹ rẹ̀ pé: o si fi Rakeli ọmọbirin rẹ̀ fun u li aya pẹlu.

29 Labani si fi Bilha, ọmọbirin ọdọ rẹ̀, fun Rakeli, ọmọbirin rẹ̀, ni iranṣẹ rẹ̀.

30 O si wọle tọ̀ Rakeli pẹlu, o si fẹ́ Rakeli jù Lea lọ, o si sìn i li ọdún meje miran si i.

31 Nigbati OLUWA si ri i pe a korira Lea, o ṣí i ni inu: ṣugbọn Rakeli yàgan.

32 Lea si loyun, o si bí ọmọkọnrin kan, o si sọ orukọ rẹ̀ ni Reubeni: nitori ti o wipe, OLUWA wò ìya mi nitõtọ: njẹ nitorina, ọkọ mi yio fẹ́ mi.

33 O si tun yún, o si bí ọmọkọnrin kan; o si wipe, Nitori ti OLUWA ti gbọ́ pe a korira mi, nitorina li o ṣe fun mi li ọmọ yi pẹlu: o si sọ orukọ rẹ̀ ni Simeoni.

34 O si tun loyun, o si bí ọmọkọnrin kan; o si wipe, Njẹ nigbayi li ọkọ mi yio faramọ́ mi, nitori ti mo bí ọmọkonrin mẹta fun u: nitorina li o ṣe sọ orukọ rẹ̀ ni Lefi.

35 O si tun yún, o si bí ọmọkọnrin kan: o si wipe, Nigbayi li emi o yìn OLUWA: nitorina li a ṣe sọ orukọ rẹ̀ ni Judah; o si dẹkun bíbi.

## ORI 30.

NIGBATI Rakeli ri pe on kò bimọ fun Jakobu, Rakeli ṣe ilara arabirin rẹ̀; o si wi fun Jakobu pe, Fun mi li ọmọ, bikoṣe bẽ emi o kú.

2 Jakobu si binu si Rakeli: o si wipe, Emi ha wà ni ipò Ọlọrun, ẹniti o dù ọ li ọmọ bíbi?

3 On si wipe, Wò Bilha iranṣẹbirin mi, wọle tọ̀ ọ; on ni yio si bí lori ẽkun mi, ki a le gbé mi ró pẹlu nipasẹ rẹ̀.

4 O si fi Bilha, iranṣẹbirin rẹ̀, fun u li aya: Jakobu si wọle tọ̀ ọ.

5 Bilha si yún, o si bí ọmọkọnrin kan fun Jakobu.

6 Rakeli si wipe, Ọlọrun ti ṣe idajọ mi, o si ti gbọ́ ohùn mi, o si fi omọkọnrin kan fun mi pẹlu: nitorina li o ṣe sọ orukọ rẹ̀ ni Dani.

7 Bilha, iranṣẹbirin Rakeli, si tun yún, o si bi ọmọkọnrin keji fun Jakobu.

8 Rakeli si wipe, Ijakadi nla ni mo fi bá arabirin mi ja, emi si dá a: o si sọ orukọ rẹ̀ ni Naftali.

9 Nigbati Lea ri pe on dẹkun ọmọ bíbi, o si mú Silpa, iranṣẹbirin rẹ̀, o si fi fun Jakobu li aya.

10 Silpa, iranṣẹbirin Lea, si bí ọmọkọnrin kan fun Jakobu.

11 Lea si wipe, Ire de: o si sọ orukọ rẹ̀ ni Gadi.

12 Silpa iranṣẹbirin Lea si bí ọmọkọnrin keji fun Jakobu.

13 Lea si wipe, Alabukún fun li emi, nitori ti awọn ọmọbirin yio ma pè mi li alabukún fun: o si sọ orukọ rẹ̀ ni Aṣeri.

14 Li akokò ìgba ikore alikama, Reubeni si lọ, o si ri eso mandraki ni igbẹ́, o si mú wọn fun Lea iya rẹ̀ wá ile. Nigbana ni Rakeli wi fun Lea pe, Emi bẹ̀ ọ, bùn mi ninu mandraki ọmọ rẹ.

15 O si wi fun u pe, Iṣe nkan kekere ti iwọ gbà ọkọ lọwọ mi? iwọ si nfẹ́ gbà mandraki ọmọ mi pẹlu? Rakeli si wipe, Nitori na ni yio ṣe sùn tì ọ li alẹ yi nitori mandraki ọmọ rẹ.

16 Jakobu si ti inu oko dé li aṣalẹ, Lea si jade lọ ipade rẹ̀ o si wipe, Iwọ kò le ṣe aima wọle tọ̀ mi wá, nitori ti emi ti fi mandraki ọmọ mi bẹ̀ ọ li ọ̀wẹ. On si sùn tì i li oru na.

17 Ọlọrun si gbọ́ ti Lea, o si yún, o si bí ọmọkọnrin karun fun Jakobu.

18 Lea si wipe, Ọlọrun san ọ̀ya mi fun mi, nitori ti mo fi iranṣẹbirin mi fun ọkọ mi; o si pè orukọ rẹ̀ ni Issakari.

19 Lea si tun yún, o si bí ọmọkọnrin kẹfa fun Jakobu.

20 Lea si wipe, Ọlọrun ti fun mi li ẹ̀bun rere; nigbayi li ọkọ mi yio tó ma bá mi gbé, nitori ti mo bí ọmọkọnrin mẹfa fun u: o si pè orukọ rẹ̀ ni Sebuluni.

21 Nikẹhin rẹ̀ li o si bí ọmọbirin kan, o si pè orukọ rẹ̀ ni Dina.

22 Ọlọrun si ranti Rakeli, Ọlọrun si gbọ́ tirẹ̀, o si ṣí i ni inu.

23 O si yún, o si bí ọmọkọnrin kan; o si wipe, Ọlọrun mú ẹ̀gan mi kuro;

24 O si pè orukọ rẹ̀ ni Josefu; o si wipe, Ki OLUWA ki o fi ọmọkọnrin kan kún u fun mi pẹlu.

25 O si ṣe, nigbati Rakeli bí Josefu tán, Jakobu si wi fun Labani pe, Rán mi jade

Digitized by Google

lọ, ki emi ki o le ma lọ si ibiti mo ti wá,
ati si ilẹ mi.
26 Fun mi li awọn obirin mi, ati awọn
ọmọ mi, nitori awọn ẹniti mo ti nsìn ọ, ki
o si jẹ ki nma lọ: iwọ sá mọ̀ ìsin ti mo
sìn ọ.
27 Labani si wipe, Duro, emi bẹ̀ ọ, bi o
ba ṣepe emi ri ore-ọfẹ li oju rẹ, joko: ni-
tori ti mo ri i pe, OLUWA ti bukún fun mi
nitori rẹ.
28 O si wi fun u pe, Sọ iye owo iṣẹ rẹ,
emi o si fi fun ọ.
29 O si wi fun u pe, Iwọ mọ̀ bi emi ti sìn
ọ, ati bi ẹran-ọ̀sin rẹ ti wà lọdọ mi.
30 Diẹ ni iwọ sá ti ní ki nto dé ọdọ rẹ,
OLUWA si busi i li ọ̀pọlọpọ fun ọ lati ìgba
ti mo ti dé: njẹ nisisiyi nigbawo li emi o
pèse fun ile mi?
31 O si bi i pe, Kili emi o fi fun ọ?
Jakobu si wi pe, Iwọ máṣe fun mi li ohun
kan: bi iwọ o ba le ṣe eyi fun mi, emi o
ma bọ́, emi o si ma ṣọ́ agbo-ẹran rẹ.
32 Emi o là gbogbo agbo-ẹran rẹ já loni,
emi o mú gbogbo ẹran abilà ati alamì kuro
nibẹ̀, ati gbogbo ẹran pupa rúsurusu kuro
ninu awọn agutan, ati gbogbo ẹran alamì
ati abilà ninu awọn ewurẹ: eyi ni yio si
ma ṣe ọ̀ya mi.
33 Ododo mi yio si jẹ mi li ẹrí li ẹhin-
ọla nigbati iwọ o wá wò ọ̀ya mi: gbogbo
eyiti kò ba ṣe abilà ati alamì ninu awọn
ewurẹ, ti kò si ṣe pupa rúsurusu ninu awọn
agutan, on na ni ki a kà si mi li ọrùn bi ole.
34 Labani si wipe, Wò o, jẹ ki o ri bi
ọ̀rọ rẹ.
35 Li ọjọ́ na li o si yà awọn obukọ oni-
tototó ati alamì, ati gbogbo awọn ewurẹ ti
o ṣe abilà ati alamì, ati gbogbo awọn ti o
ní funfun diẹ lara, ati gbogbo oni-pupa
rúsurusu ninu awọn agutan, o si fi wọn lé
awọn ọmọ rẹ̀ lọwọ.
36 O si fi ìrin ọjọ́ mẹta si agbedemeji on
tikalarẹ̀ ati Jakobu: Jakobu si mbọ́ agbo-
ẹran Labani iyokù.
37 Jakobu si mú ọpá igi-poplari tutù,
ati igi haseli, ati kesnuti; o si bó wọn li
abófin, o si mu ki funfun ti o wà lara awọn
ọpá na hàn.
38 O si fi ọpá ti o bó lelẹ niwaju awọn
agbo-ẹran li oju àgbará, ni ibi ọkọ̀ imumi,
nigbati awọn agbo-ẹran wá mu omi, ki
nwọn ki o le yún nigbati nwọn ba wá
mumi.
39 Awọn agbo-ẹran si yún niwaju ọpá
wọnni, nwọn si bí ẹran oni-tototó, ati abilà,
ati alamì.
40 Jakobu si yà awọn ọdọ-agutan, o si
kọju awọn agbo-ẹran si oni-tototó, ati gbo-
gbo onipupa rúsurusu ninu agbo-ẹran La-
bani: o si fi awọn agbo-ẹran si ọ̀tọ fun ara
rẹ̀, kò si fi wọn sinu ẹran Labani.
41 O si ṣe, nigbati ẹran ti o lera jù ba
yún, Jakobu a si fi ọpá na lelẹ niwaju awọn
ẹran na li oju àgbará, ki nwọn o le ma yún
lãrin ọpá wọnni.
42 Ṣugbọn nigbati awọn ẹran ba ṣe alai-
lera, on ki ifi si i; bẹ̃li ailera ṣe ti Labani,
awọn ti o lera jẹ́ ti Jakobu.
43 Ọkọnrin na si pọ̀ gidigidi, o si li
ẹran-ọ̀sin pupọ̀, ati iranṣẹbirin, ati iranṣẹ-
kọnrin, ati ibakasiẹ, ati kẹtẹkẹtẹ.

## ORI 31.

O SI gbọ́ ọ̀rọ awọn ọmọ Labani ti nwọn
wipe, Jakobu kó nkan gbogbo ti iṣe ti
baba wa; ati ninu ohun ti iṣe ti baba wa
li o ti ní gbogbo ọrọ̀ yi.
2 Jakobu si wò oju Labani, si kiyesi i,
kò ri si i bi ìgba atijọ.
3 OLUWA si wi fun Jakobu pe, Pada lọ
si ilẹ awọn baba rẹ, ati si ọdọ awọn ará rẹ;
emi o si pẹlu rẹ.
4 Jakobu si ranṣẹ o si pè Rakeli on Lea
si pápa si ibi agbo-ẹran rẹ̀,
5 O si wi fun wọn pe, Emi wò oju baba
nyin pe, kò ri si mi bi ìgba atijọ; ṣugbọn
Ọlọrun baba mi ti wà pẹlu mi.
6 Ẹnyin si mọ̀ pe gbogbo agbara mi li
emi fi sìn baba nyin.
7 Baba nyin si ti tàn mi jẹ, o si pa ọ̀ya
mi dà nigba mẹwa: ṣugbọn Ọlọrun kò jẹ
ki o pa mi lara.
8 Bi o ba si wi bayi pe, Awọn abilà ni
yio ṣe ọ̀ya rẹ: gbogbo awọn ẹran a si bí
abilà: bi o ba si wi bayi, Awọn oni-tototó
ni yio ṣe ọ̀ya rẹ; gbogbo awọn ẹran a si bí
oni-tototó.
9 Bẹ̃li Ọlọrun si gbà ẹran baba nyin, o
si fi wọn fun mi.
10 O si ṣe li akokò ti awọn ẹran yún,
mo si gbé oju mi soke, mo si ri li oju-alá,
si kiyesi i, awọn obukọ ti o ngùn awọn
ẹran jẹ́ oni-tototó, abilà, ati alamì.
11 Angeli Ọlọrun si sọ fun mi li oju-alá
pe, Jakobu: emi si wipe, Emi niyi.
12 O si wipe, Gbé oju rẹ soke nisisiyi,
ki o si wò, gbogbo awọn obukọ ti ngùn
awọn ẹran li o ṣe tototó, abilà, ati alami:
nitori ti emi ti ri ohun gbogbo ti Labani
nṣe si ọ.
13 Emi li Ọlọrun Beteli, nibiti iwọ gbé
ta oróro si ọwọ̀n, nibiti iwọ gbe jẹ́ ẹjẹ́ fun

Digitized by Google

mi: dide nisisiyi, jade kuro ni ilẹ yi, ki o
si pada lọ si ilẹ ti a bi ọ.
14 Rakeli ati Lea si dahùn nwọn si wi
fun u pe, Ipín, tabi ogún kan ha tun kù
fun wa mọ́ ni ile baba wa?
15 Alejò ki on nkà wa si? nitori ti o ti
tà wa; o si ti mù owo wa jẹ gúdugudu.
16 Nitori ọrọ̀ gbogbo ti Ọlọrun ti gbà
lọwọ baba wa, eyinì ni ti wa, ati ti awọn
ọmọ wa: njẹ nisisiyi ohunkohun ti Ọlọrun
ba sọ fun ọ, on ni ki o ṣe.
17 Nigbana ni Jakobu dide, o si gbé
awọn ọmọ rẹ̀ ati awọn aya rẹ̀ gùn ibakasiẹ.
18 O si kó gbogbo ẹran rẹ̀ lọ, ati gbogbo
ẹrù ti o ní, ẹran ti o ní fun ara rẹ̀ ti o ní
ni Padan-aramu, lati ma tọ̀ Isaaki baba rẹ̀
lọ ni ilẹ Kenaani.
19 Labani si lọ irẹrun agutan rẹ̀: Ra-
keli si ti jí awọn ere baba rẹ̀ lọ.
20 Jakobu si tàn Labani ara Siria jẹ niti
pe kò wi fun u ti o fi salọ.
21 Bẽli o kó ohun gbogbo ti o ní salọ:
o si dide, o si kọja odò, o si kọju rẹ̀ si oke
Gileadi.
22 A si wi fun Labani ni ijọ́ kẹta pe,
Jakobu salọ.
23 O si mú awọn arakọnrin rẹ̀ pẹlu rẹ̀,
o si lepa rẹ̀ ni ìrin ijọ́ meje: o si bá a li
oke Gileadi.
24 Ọlọrun si tọ̀ Labani, ara Siria wá li
oru li oju-alá, o si wi fun u pe, Kiyesi ara
rẹ, ki iwọ ki o máṣe ba Jakobu sọ rere tabi
buburu.
25 Nigbana ni Labani bá Jakobu. Ja-
kobu ti pa agọ́ rẹ̀ li oke na: ati Labani
pẹlu awọn arakọnrin rẹ̀ dó li oke Gileadi.
26 Labani si wi fun Jakobu pe, Kini iwọ
ṣe nì, ti iwọ tàn mi jẹ ti iwọ si kó awọn
ọmọbirin mi lọ bi ìgbẹsin ti a fi idà mú?
27 Ẽṣe ti iwọ fi salọ li aṣíri, ti iwọ si tàn
mi jẹ; ti iwọ kò si wi fun mi ki emi ki o
le fi ayọ̀ ati orin, ati ìlu, ati dùru, sìn ọ;
28 Ti iwọ kò si jẹ ki emi fi ẹnu kò awọn
ọmọkọnrin ati ọmọbirin mi li ẹnu? iwọ
ṣiwere li eyiti iwọ ṣe yi.
29 O wà ni ipa mi lati ṣe nyin ni ibi:
ṣugbọn Ọlọrun baba nyin ti sọ fun mi li
oru aná pe, Kiyesi ara rẹ ki iwọ ki o máṣe
bá Jakobu sọ rere tabi buburu.
30 Ati nisisiyi, iwọ kò le ṣe ailọ, nitori
ti ọkàn rẹ fà gidigidi si ile baba rẹ, ṣugbọn
ẽhaṣe ti iwọ fi jí awọn oriṣa mi lọ?
31 Jakobu si dahùn o si wi fun Labani
pe, Nitori ti mo bẹ̀ru ni: nitori ti mo
wipe, iwọ le fi agbara gbà awọn ọmọbirin
rẹ lọwọ mi.
32 Lọwọ ẹnikẹni ti iwọ ba ri awọn oriṣa
rẹ ki o máṣe wà lãye: li oju awọn arakọn-
rin wa wọnyi, wá ohun ti iṣe tirẹ lọdọ mi,
ki o si mú u si ọdọ rẹ. Jakobu kò sa mọ̀
pe Rakeli ti jí wọn.
33 Labani si wọ̀ inu agọ́ Jakobu lọ, ati
inu agọ́ Lea, ati inu agọ́ awọn iranṣẹbirin
mejeji; ṣugbọn kò ri wọn. Nigbana li o
jade kuro ninu agọ́ Lea, o si wọ̀ inu agọ́
Rakeli lọ.
34 Rakeli si gbé awọn ere na, o si fi wọn
sinu gãri ibakasiẹ, o si joko le wọn. La-
bani si wá gbogbo agọ́ ṣugbọn kò ri wọn.
35 O si wi fun baba rẹ̀ pe, Oluwa mi,
máṣe jẹ ki o bi ọ ninu nitori ti emi kò le
dide niwaju rẹ; nitori ti iṣe obirin mbẹ
lara mi. O si wá agọ́ kiri, ṣugbọn kò ri
awọn ere na.
36 Inu si bi Jakobu, o si bá Labani sọ̀:
Jakobu si dahùn o wi fun Labani pe, Kini
irekọja ma? kili ẹ̀ṣẹ mi ti iwọ fi lepa mi
wìriwiri bẹ̃?
37 Njẹ bi iwọ ti tú ẹrù mi gbogbo, kili
iwọ ri ninu gbogbo nkan ile rẹ? gbé e kalẹ
nihinyi niwaju awọn arakọnrin rẹ, ki nwọn
ki o le ṣe idajọ rẹ̀ fun awa mejeji.
38 Ogún ọdún yi ni mo ti wà lọdọ rẹ:
agutan rẹ ati ewurẹ rẹ kò ṣẹnu, agbo ọwọ́-
ẹran rẹ li emi kò si pajẹ.
39 Eyiti ẹranko fàya emi kò mú u fun
ọ wá; emi li o gbà òfo rẹ̀; li ọwọ́ mi ni
iwọ bère rẹ̀, a ba jí i li ọsán, a ba jí i li
oru.
40 Bayi ni mo wà; ongbẹ ngbẹ mi li
ọsán, otutù si nmu mi li oru: orun mi si
dá kuro li oju mi.
41 Bayi li o ri fun mi li ogún ọdún ni
ile rẹ: mo sìn ọ li ọdún mẹrinla nitori
awọn ọmọbirin rẹ mejeji, ati li ọdún mẹfa
nitori ohunọ̀sin rẹ: iwọ si pa ọ̀ya mi dà
nigba mẹwa.
42 Bikoṣe bi Ọlọrun baba mi, Ọlọrun
Abrahamu, ati ẹ̀ru Isaaki ti wà pẹlu mi,
nitõtọ ofo ni iwọ iba rán mi jade lọ. Ọlọ-
run ri ipọnju mi, ati lãla ọwọ́ mi, o si ba ọ
wi li oru aná.
43 Labani si dahùn o si wi fun Jakobu
pe, Awọn ọmọbirin wọnyi, awọn ọmọbirin
mi ni, ati awọn ọmọ wọnyi, awọn ọmọ mi
ni, ati awọn ọwọ́-ẹran wọnyi ọwọ́-ẹran mi
ni, ati ohun gbogbo ti o ri ti emi ni: kili
emi iba si ṣe si awọn ọmọbirin mi wọnyi
loni, tabi si awọn ọmọ wọn ti nwọn bí?
44 Njẹ nisisiyi, wá, jẹ ki a bá ara wa dá
majẹmu, temi tirẹ; ki o si ṣe ẹrí lãrin temi
tirẹ.

Digitized by Google

45 Jakobu si mú okuta kan, o si gbé e
ró ṣe ọwọ̀n.
46 Jakobu si wi fun awọn arakọnrin rẹ̀
pe, Ẹ ma kó okuta jọ; nwọn si kó okuta
jọ, nwọn si ṣe òkiti: nwọn si jẹun nibẹ̀ lori
òkiti na.
47 Labani si sọ orukọ rẹ̀ ni Jegari-Saha-
duta: ṣugbọn Jakobu sọ ọ ni Galeedi.
48 Labani si wipe, Òkiti yi li ẹri lãrin
temi tirẹ loni. Nitori na li a ṣe sọ orukọ
rẹ̀ ni Galeedi:
49 Ati Mispa; nitori ti o wipe, Ki
OLUWA ki o ma ṣọ́ temi tirẹ, nigbati a o yà
kuro lọdọ ara wa.
50 Bi iwọ ba pọ́n awọn ọmọbirin mi li
oju, tabi bi iwọ ba fẹ́ aya miran pẹlu awọn
ọmọbirin mi, kò si ẹnikan pẹlu wa; wò o,
Ọlọrun li ẹlẹri lãrin temi tirẹ.
51 Labani si wi fun Jakobu pe, Wò òkiti
yi, si wò ọwọ̀n yi, ti mo gbé ró lãrin temi
tirẹ.
52 Òkiti yi li ẹri, ọwọ̀n yi li ẹri, pe emi
ki yio rekọja òkiti yi sọdọ rẹ; ati pe iwọ
ki yio si rekọja òkiti yi ati ọwọ̀n yi sọdọ
mi fun ibi.
53 Ọlọrun Abrahamu, ati Ọlọrun Na-
hori, Ọlọrun baba wọn, ni ki o ṣe idajọ
lãrin wa. Jakobu si fi ẹ̀ru Isaaki baba rẹ̀
bura.
54 Nigbana ni Jakobu rubọ lori oke na,
o si pè awọn arakọnrin rẹ̀ wá ijẹun: nwọn
si jẹun, nwọn si fi gbogbo oru ijọ́ na sùn
lori oke na.
55 Ni kutukutu owurọ̀ Labani si dide, o
si fi ẹnu kò awọn ọmọkọnrin, ati awọn
ọmọbirin rẹ̀ li ẹnu, o si sure fun wọn:
Labani si dide, o si pada lọ si ipò rẹ̀.

## ORI 32.

JAKOBU si nlọ li ọ̀na rẹ̀, awọn angeli
Ọlọrun si pade rẹ̀.
2 Nigbati Jakobu si ri wọn, o ni, Ogun
Ọlọrun li eyi: o si sọ orukọ ibẹ̀ na ni
Mahanaimu.
3 Jakobu si ranṣẹ siwaju rẹ̀ si Esau, ara-
kọnrin rẹ̀, si ilẹ Seiri, pápa oko Edomu.
4 O si rán wọn wipe, Bayi ni ki ẹnyin
ki o wi fun Esau, oluwa mi; Bayi ni
Jakobu iranṣẹ rẹ wi, Mo ti ṣe atipo lọdọ
Labani, mo si ti ngbé ibẹ̀ titi o fi di
isisiyi:
5 Mo si ní malu, ati kẹtẹkẹte, ati agbo-
ẹran, ati iranṣẹkọnrin, ati iranṣẹbirin: mo
si ranṣẹ wá wi fun oluwa mi, ki emi ki o le
ri ore-ọfẹ li oju rẹ.
6 Awọn onṣẹ si pada tọ̀ Jakobu wá,
wipe, Awa dé ọdọ Esau, arakọnrin rẹ, o
si mbọ̀wá kò ọ, irinwo ọkọnrin li o si wà
pẹlu rẹ̀.
7 Nigbana li ẹ̀ru bà Jakobu gidigidi, ãjo
si mú u, o si pín awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀,
ati awọn ọwọ́-ẹran, awọn ọwọ́-malu, ati
awọn ibakasiẹ, si ipa meji;
8 O si wipe, bi Esau ba kàn ẹgbẹ kan, ti
o si kọlù u, njẹ ẹgbẹ keji ti o kù yio là.
9 Jakobu si wipe, Ọlọrun Abrahamu ba-
ba mi, ati Ọlọrun Isaaki baba mi, OLUWA
ti o wi fun mi pe, pada lọ si ilẹ rẹ, ati sọdọ
awọn ará rẹ, emi o si ṣe ọ ni rere:
10 Emi kò yẹ si kikini ninu gbogbo ãnu,
ati ninu gbogbo otitọ, ti iwọ fihàn fun
ọmọ-ọdọ rẹ, nitori pe, kìki ọpá mi ni mo
fi kọja Jordani yi; nisisiyi emi si di ẹgbẹ
meji.
11 Emi bẹ̀ ọ, gbà mi lọwọ arakọnrin mi,
lọwọ Esau: nitori ti mo bẹ̀ru rẹ̀, ki o má
ba wá lati kọlù mi, ti iya ti ọmọ.
12 Iwọ si wipe, Nitõtọ emi o ṣe ọ ni rere,
emi o si ṣe irú-ọmọ rẹ bi iyanrin okun, ti a
kò le kà fun ọ̀pọlọpọ.
13 O si sùn nibẹ̀ li alẹ ijọ́ na; o si mú
ninu ohun ti o tẹ̀ ẹ li ọwọ li ọrẹ fun Esau,
arakọnrin rẹ̀;
14 Igba ewurẹ, on ogún obukọ, igba
agutan, on ogún àgbo,
15 Ọgbọ̀n ibakasiẹ ti o ní wàra, pẹlu
awọn ọmọ wọn, ogoji abo-malu on akọ-malu
mẹwa, ogún abo-kẹtẹkẹtẹ, on ọmọ-kẹtẹkẹtẹ
mẹwa.
16 O si fi wọn lé ọwọ́ awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀,
ọlọwọ́-ọwọ́; o si wi fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀
pe, Ẹnyin ṣaju mi, ki ẹ si bù afo si agbede-
meji ọwọ́-ọwọ.
17 O si fi aṣẹ fun eyiti o tète ṣaju wipe,
Nigbati Esau, arakọnrin mi, ba pade rẹ, ti
o si bi ọ wipe, Ti tani iwọ? nibo ni iwọ si
nrè? ati ti tani wọnyi niwaju rẹ?
18 Nigbana ni ki iwọ ki o wipe, Ti Jako-
bu iranṣẹ rẹ ni; ọrẹ ti o rán si Esau oluwa
mi ni: si kiyesi i, on tikalarẹ̀ si mbẹ
lẹhin wa.
19 Bẹ̃li o si fi aṣẹ fun ekeji, ati fun ẹkẹta,
ati fun gbogbo awọn ti o tẹle ọwọ́ wọnni
wipe, Bayibayi ni ki ẹnyin ki o wi fun Esau
nigbati ẹnyin ba ri i.
20 Ki ẹnyin ki o wi pẹlu pe, Kiyesi i,
Jakobu iranṣẹ rẹ mbọ̀ lẹhin wa. Nitori ti
o wipe, Emi o fi ọrẹ ti o ṣaju mi tù u loju,
lẹhin eyini emi o ri oju rẹ̀, bọya yio tẹwọ-
gbà mi.
21 Bẹ̃li ọrẹ na si kọja lọ niwaju rẹ̀: on
tikalarẹ̀ si sùn li oru na ninu awọn ẹgbẹ.

Digitized by Google

22 O si dide li oru na, o si mú awọn aya
rẹ̀ mejeji, ati awọn iranṣẹbirin rẹ̀ mejeji,
ati awọn ọmọ rẹ̀ mọkọkanla, o si kọja iwọdò
Jabboku.
23 O si mú wọn, o si rán wọn si oke odò
na, o si rán ohun ti o ní kọja si oke odò.
24 O si kù Jakobu nikan; ọkọnrin kan
si mbá a jijakadi titi o fi di afẹmọjumọ.
25 Nigbati o si ri pe on kò le dá a, o
fọwọkàn a ni ihò egungun itan rẹ̀; ihò
egungun itan Jakobu si yẹ̀ li orike bi o ti
mbá a jijakadi.
26 O si wipe, Jẹ ki emi ki o lọ nitori
ti ojúmọ mọ́ tán. On si wipe, Emi ki
yio-jẹ ki iwọ ki o lọ, bikoṣepe iwọ ba sure
fun mi.
27 O si bi i pe, Orukọ rẹ? On si dahùn
pe, Jakobu.
28 O si wipe, A ki yio pè orukọ rẹ ni
Jakobu mọ́, bikoṣe Israeli: nitoripe, iwọ ti
ba Ọlọrun ati enia jà, iwọ si bori.
29 Jakobu si bi i o si wipe, Emi bẹ̀ ọ,
sọ orukọ rẹ fun mi. On si wipe, Ẽṣe ti
iwọ fi mbère orukọ mi? o si sure fun u
nibẹ̀.
30 Jakobu si sọ orukọ ibẹ̀ na ni Penieli:
o ni, Nitori ti mo ri Ọlọrun li ojukoju, a si
dá ẹmi mi si.
31 Bi o si ti nkọja Penieli, õrùn là ba a,
o si nmukun ni itan rẹ̀.
32 Nitori na li awọn ọmọ Israeli ki iṣe
ijẹ iṣan ti ifà, ti o wà ni kòto itan, titi o fi
di oni-oloni: nitori ti o fọwọkàn kòto
egungun itan Jakobu ni iṣan ti ifà.

## ORI 33.

JAKOBU si gbé oju rẹ̀ soke, o si wò, si
kiyesi i, Esau dé, ati irinwo ọkọnrin
pẹlu rẹ̀. On si pín awọn ọmọ fun Lea,
ati fun Rakeli, ati fun awọn iranṣẹbirin
mejeji.
2 O si tì awọn iranṣẹbirin ati awọn ọmọ
wọn ṣaju, ati Lea ati awọn ọmọ rẹ̀ tẹle wọn,
ati Rakeli ati Josefu kẹhin.
3 On si kọja lọ siwaju wọn, o si wolẹ li
ẹrinmeje titi o fi dé ọdọ arakọnrin rẹ̀.
4 Esau si sure lati pade rẹ̀, o si gbá a mú
o si rọmọ́ ọ li ọrùn, o si fi ẹnu kò o li ẹnu:
nwọn si sọkun.
5 O si gbé oju rẹ̀ soke, o si ri awọn obirin
ati awọn ọmọ; o si bi i pe, Tani wọnyi pẹlu
rẹ? On si wipe, Awọn ọmọ ti Ọlọrun fi
ore-ọfẹ fun iranṣẹ rẹ ni.
6 Nigbana li awọn iranṣẹbirin sunmọ
ọdọ rẹ̀, awọn ati awọn ọmọ wọn, nwọn si
tẹriba.
7 Ati Lea pẹlu ti on ti awọn ọmọ rẹ̀
sunmọ ọdọ rẹ̀, nwọn si tẹriba: nikẹhin ni
Josefu ati Rakeli si sunmọ ọdọ rẹ̀, nwọn si
tẹriba.
8 O si wipe, Kini iwọ fi ọwọ́ ti mo pade
nì pè? On si wipe, Lati fi ri ore-ọfẹ li oju
oluwa mi ni.
9 Esau si wipe, Emi ní tó, arakọnrin mi;
pa eyiti o ní mọ́ fun ara rẹ.
10 Jakobu si wipe, Bẹ̃kọ, emi bẹ̀ ọ, bi o
ba ṣepe emi ba ri ore-ọfẹ li oju rẹ nisisiyi,
njẹ gbà ọrẹ mi lọwọ mi: nitori ti emi sa ri
oju rẹ bi ẹnipe emi ri oju Ọlọrun, ti inu rẹ
si dùn si mi;
11 Emi bẹ̀ ọ, gbà ẹ̀bun mi ti a mú fun
ọ wá; nitori ti Ọlọrun fi ore-ọfẹ ba mi ṣe,
ati pe, nitori ti mo ní tó. O si rọ̀ ọ, on si
gbà a.
12 O si wipe, Jẹ ki a bọ́ si ọ̀na irin wa,
ki a si ma lọ, emi o si ṣaju rẹ.
13 Ṣugbọn on wi fun u pe, oluwa mi mọ̀
pe awọn ọmọ kò lera, ati awọn agbo-ẹran,
ati ọwọ́-malu ati awọn ọmọ wọn wà pẹlu
mi: bi enia ba si dà wọn li àdaju li ọjọ́
kan, gbogbo agbo ni yio kú.
14 Emi bẹ̀ o, ki oluwa mi ki o ma kọja
nṣó niwaju iranṣẹ rẹ̀: emi o si ma fà wá
pẹlẹ, gẹgẹ bi awọn ẹran ti o saju mi, ati bi
ara awọn ọmọ ti le gbà, titi emi o fi dé
ọdọ oluwa mi ni Seiri.
15 Esau si wipe, Njẹ ki emi ki o fi enia
diẹ silẹ pẹlu rẹ ninu awọn enia ti o pẹlu
mi. On si wipe, Nibo li eyini jasi? ki emi
ki o sa ri ore-ọfẹ li oju oluwa mi.
16 Esau si pada li ọjọ́ na li ọ̀na rẹ̀ lọ si
Seiri.
17 Jakobu si rìn lọ si Sukkotu, o si kọ́
ile fun ara rẹ̀, o si pa agọ́ fun awọn ẹran
rẹ̀: nitorina li a ṣe sọ orukọ ibẹ̀ na ni
Sukkotu.
18 Jakobu si wá li alafia, si ilu Ṣekemu
ti o wà ni ilẹ Kenaani, nigbati o ti Padan-
aramu bọ̀dé: o si pa agọ́ rẹ̀ niwaju ilu na.
19 O si rà oko biri kan, nibiti o gbé ti
pa agọ́ rẹ̀ lọwọ awọn ọmọ Hamori, baba
Ṣekemu, li ọgọrun owo fadaka.
20 O si tẹ́ pẹpẹ kan sibẹ̀, o si sọ orukọ
rẹ̀ ni El-Elohe-Israeli.

## ORI 34.

DINA ọmọbirin Lea, ti o bí fun Jakobu
si jade lọ lati wò awọn ọmọbirin ilu
na.
2 Nigbati Ṣekemu, ọmọ Hamori, ara
Hiffi, ọmọ alade ilu na ri i, o mú u, o si
wọle tọ̀ ọ, o si bà a jẹ́.



Digitized by Google

3 Ọkàn rẹ̀ si fà mọ́ Dina, ọmọbirin Ja-
kobu, o si fẹ́ ọmọdan na, o si sọ̀rọ rere fun
ọmọdan na.
4 Ṣekemu si sọ fun Hamori baba rẹ̀ pe,
Fẹ́ ọmọdan yi fun mi li aya.
5 Jakobu si gbọ́ pe o ti bà Dina ọmọ-
birin on jẹ́ ; njẹ awọn ọmọ rẹ̀ wà pẹlu awọn
ẹran ni pápa : Jakobu si pa ẹnu rẹ̀ mọ́ titi
nwọn fi dé.
6 Hamori, baba Ṣekemu, si jade tọ̀ Ja-
kobu lọ lati bá a sọ̀rọ.
7 Awọn ọmọ Jakobu si ti oko dé nigbati
nwọn gbọ́ : inu awọn ọkọnrin na si bàjẹ́,
inu si ru wọn gidigidi, nitori ti o ṣe ohun
buburu ni Israeli, niti o bá ọmọbirin Ja-
kobu dàpọ : ohun ti a ki ba ti ṣe.
8 Hamori si bá wọn sọ̀rọ pe, Ọkàn Ṣe-
kemu, ọmọ mi, nfẹ́ ọmọbirin nyin ; emi bẹ̀
nyin, ẹ fi i fun u li aya.
9 Ki ẹnyin ki o si bá wa gbeyawo, ki
ẹnyin ki o si fi awọn ọmọbirin nyin fun
wa, ki ẹnyin ki o si ma mú awọn ọmọbirin
wa.
10 Ẹnyin o si ma bá wa gbé : ilẹ yio si
wà niwaju nyin, ẹnyin o joko ki ẹ si ma
ṣòwo ninu rẹ̀, ki ẹ si ma ní iní ninu rẹ̀.
11 Ṣekemu si wi fun baba ọmọdan na
ati fun awọn arakọnrin rẹ̀ pe, Ẹ jẹ ki emi
ri ore-ọfẹ li oju nyin, ohun ti ẹnyin o si kà
fun mi li emi o fi fun nyin.
12 Ẹ bère ana lọwọ mi ati ẹ̀bun bi o ti
wù ki o pọ̀ to, emi o si fi fun nyin gẹgẹ bi
ẹnyin o ti kà fun mi : ṣugbọn ẹ fun mi li
ọmọdan na li aya.
13 Awọn ọmọ Jakobu si fi ẹ̀tan da Ṣe-
kemu ati Hamori baba rẹ̀ lohùn, nwọn si
wipe, nitori ti o bà Dina arabirin wọn jẹ́ :
14 Nwọn si wi fun wọn pe, Awa kò le
ṣe nkan yi lati fi arabirin wa fun ẹni alai-
kọlà, nitori ohun àbuku ni fun wa ;
15 Kìki ninu eyi li awa le jẹ fun nyin :
bi ẹnyin o ba wà bi awa, pe ki a kọ oluku-
luku ọkọnrin nyin ni ilà.
16 Nigbana li awa o fi awọn ọmọbirin
wa fun nyin, awa o si mú awọn ọmọbirin
nyin sọdọ wa ; awa o si ma bá nyin gbé,
awa o si di enia kanna.
17 Ṣugbọn bi ẹnyin kò ba gbọ́ ti wa lati
kọlà ; njẹ awa o mú ọmọbirin wa, awa o si
ba ti wa lọ.
18 Ọrọ wọn si dùn mọ́ Hamori, ati Ṣe-
kemu, ọmọ Hamori.
19 Ọdọmọkọnrin na kò si pẹ́ titi lati ṣe
nkan na, nitoriti o fẹ́ ọmọbirin Jakobu ; o
si li ọlá jù gbogbo ara ile baba rẹ̀ lọ.
20 Ati Hamori ati Ṣekemu ọmọ rẹ̀ wá si
ẹnubode ilu wọn, nwọn si bá awọn ara ilu
wọn sọ̀rọ wipe,
21 Awọn ọkọnrin wọnyi mbá wa gbé li
alafia ; nitorina ẹ jẹ ki nwọn ki o ma gbé
ilẹ yi, ki nwọn ki o si ma ṣòwo nibẹ̀ ; ki-
yesi i, ilẹ sa gbàyè tó niwaju wọn ; ẹnyin
jẹ ki a ma fẹ́ awọn ọmọbirin wọn li aya, ki
awa ki o si ma fi awọn ọmọbirin wa fun
wọn.
22 Kìki ninu eyi li awọn ọkọnrin na o
ṣe jẹ fun wa, lati ma bá wa gbé lati di enia
kan, bi gbogbo ọkọnrin inu wa ba kọlà,
gẹgẹ bi nwọn ti kọlà.
23 Ti wa kọ ẹran wọn, ati ẹrù wọn, ati
gbogbo ohunọ̀sin wọn yio ha ṣe ? ki a sa jẹ
fun wọn, nwọn o si ma ba wa joko.
24 Gbogbo awọn ti njade li ẹnubode ilu
wọn si fetisi ti Hamori ati ti Ṣekemu ọmọ
rẹ̀ ; a si kọ gbogbo awọn ọkọnrin ni ilà,
gbogbo ẹniti o nti ẹnubode wọn jade.
25 O si ṣe ni ọjọ́ kẹta, ti ọgbẹ wọn kan,
ni awọn ọmọkọnrin Jakobu meji si dide,
Simeoni ati Lefi, awọn arakọnrin Dina,
olukuluku nwọn mú idà rẹ̀, nwọn si fi
igboyà wọ̀ ilu na, nwọn si pa gbogbo awọn
ọkọnrin.
26 Nwọn si fi oju idà pa Hamori ati
Ṣekemu, ọmọ rẹ̀, nwọn si mú Dina jade
kuro ni ile Ṣekemu, nwọn si jade lọ.
27 Awọn ọmọ Jakobu si wọle awọn ti a
pa, nwọn si kó ilu na lọ, nitori ti nwọn bà
arabirin wọn jẹ́.
28 Nwọn kó agutan wọn, ati akọmalu
wọn, ati kẹtẹkẹtẹ wọn, ati ohun ti o wà ni
ilu na, ati eyiti o wà li oko.
29 Ati ọrọ̀ wọn gbogbo, ati gbogbo ọmọ
wọn wẹrẹ, ati aya wọn, ni nwọn dì ni igbe-
kun, nwọn si kó ohun gbogbo ti o wà ninu
ile lọ.
30 Jakobu si wi fun Simeoni on Lefi pe,
Ẹnyin mu wahalà bá mi niti ẹnyin mu mi
di õrun ninu awọn onilẹ, ninu awọn ara
Kenaani ati awọn enia Perissi : bi emi kò
si ti pọ̀ ni iye, nwọn o kó ara wọn jọ si mi,
nwọn o si pa mi : a o si pa mi run, emi
ati ile mi.
31 Nwọn si wipe, Ki on ki o ha ṣe si
arabirin wa bi ẹnipe si panṣaga ?

## ORI 35.

OLỌRUN si wi fun Jakobu pe, Dide goke
lọ si Beteli ki o si joko nibẹ̀, ki o si
tẹ́ pẹpẹ kan nibẹ̀, fun Ọlọrun, ti o farahàn
ọ, nigbati iwọ sá kuro niwaju Esau, ara-
kọnrin rẹ.
2 Nigbana ni Jakobu wi fun awọn ara

Digitized by Google

ile rẹ̀, ati fun gbogbo awọn ti o wà li ọdọ
rẹ̀ pe, Ẹ mú àjeji oriṣa ti o wà lọwọ nyin
kuro, ki ẹnyin ki o si sọ ara nyin di mimọ́,
ki ẹnyin ki o si pa aṣọ nyin dà:
3 Ẹ si jẹ ki a dide, ki a si goke lọ si
Beteli; nibẹ̀ li emi o si gbé tẹ́ pẹpẹ kan
fun Ọlọrun ti o da mi li ohùn li ọjọ́ ipọnju
mi, ẹniti o si wà pelu mi li àjo ti mo rè.
4 Nwọn si fi gbogbo àjeji oriṣa ti o wà
lọwọ wọn fun Jakobu, ati gbogbo oruka
eti ti o wà li eti wọn: Jakobu si pa wọn
mọ́ li abẹ igi oaku ti o wà leti Ṣekemu.
5 Nwọn si rìn lọ: ẹ̀ru Ọlọrun si mbẹ
lara ilu ti o yi wọn ká, nwọn kò si lepa
awọn ọmọ Jakobu.
6 Bẹ̃ni Jakobu si wá si Lusi, ti o wà ni
ilẹ Kenaani, eyinì ni Beteli, on ati gbogbo
enia ti o wà lọdọ rẹ̀.
7 O si tẹ́ pẹpẹ kan nibẹ̀, o si sọ orukọ
ibẹ̀ na ni El-bet-el: nitori pe nibẹ̀ li Ọlọ-
run tọ̀ ọ wá, nigbati o sá kuro niwaju
arakọnrin rẹ̀.
8 Ṣugbọn Debora olutọ́ Rebeka kú, a si
sin i nisalẹ Beteli labẹ igi oaku kan: oru-
kọ rẹ̀ a si ma jẹ́ Alloni-bakutu.
9 Ọlọrun si tún farahàn Jakobu, nigbati
o ti Padan-aramu bọ̀, o si sure fun u.
10 Ọlọrun si wi fun u pe, Jakobu li
orukọ rẹ: a ki yio pè orukọ rẹ ni Jakobu
mọ́, bikoṣe Israeli li orukọ rẹ yio ma jẹ́:
o si sọ orukọ rẹ̀ ni Israeli.
11 Ọlọrun si wi fun u pe, Emi li Ọlọrun
Olodumare: ma bisi i, si ma rẹ̀; orilẹ̀-
ède, ati ẹgbẹ-ẹgbẹ orilẹ ède ni yio ti ọdọ
rẹ wá, awọn ọba yio si ti inu rẹ jade wá;
12 Ati ilẹ ti mo ti fi fun Abrahamu ati
Isaaki, iwọ li emi o fi fun, ati irú-ọmọ rẹ
lẹhin rẹ li emi o fi ilẹ na fun.
13 Ọlọrun si lọ soke kuro lọdọ rẹ̀ ni ibi
ti o gbé mbá a sọ̀rọ.
14 Jakobu si fi ọwọ̀n kan lelẹ ni ibi ti o
gbé bá a sọ̀rọ, ani ọwọ̀n okuta: o si ta ọrẹ
ohun mimu si ori rẹ̀, o si ta oróro si ori rẹ̀.
15 Jakobu si sọ orukọ ibi ti Ọlọrun gbé
bá a sọ̀rọ ni Beteli.
16 Nwọn si rìn lati Beteli lọ: o si kù
diẹ ki nwọn ki o dé Efrati: ibi si tẹ̀ Ra-
keli: ò si ṣoro jọjọ fun u:
17 O si ṣe nigbati o wà ninu irọbí, ni
iyãgba wi fun u pe, Máṣe bẹ̀ru: iwọ o si li
ọmọkọnrin yi pẹlu.
18 O si ṣe, bi ọkàn rẹ̀ ti nlọ̀ (o sa kú) o
sọ orukọ rẹ̀ ni Ben-oni: ṣugbọn baba rẹ̀ sọ
ọ ni Benjamini.
19 Rakeli si kú, a si sin i li ọ̀na Efrati,
ti iṣe Betlehemu.
20 Jakobu si fi ọwọ̀n kan lelẹ li oju-õri
rẹ̀, eyinì ni Ọwọ̀n oju-õri Rakeli titi di
oni-oloni.
21 Israeli si nrìn lọ, o si pa agọ́ rẹ̀ nìwa-
ju ile iṣọ Ederi.
22 O si ṣe nigbati Israeli joko ni ilẹ na,
Reubeni si wọle tọ̀ Bilha, àle baba rẹ̀ lọ;
Israeli si gbọ́. Njẹ awọn ọmọ Jakobu jẹ́
mejila.
23 Awọn ọmọ Lea; Reubẹni akọ́bi Jako-
bu, ati Simeoni, ati Lefi, ati Judah, ati
Issakari, ati Sebuluni.
24 Awọn ọmọ Rakeli; Josefu, ati Ben-
jamini:
25 Ati awọn ọmọ Bilha, iranṣẹbirin Ra-
keli; Dani, ati Naftali:
26 Ati awọn ọmọ Silpa, iranṣẹbirin Lea;
Gadi ati Aṣeri. Awọn wọnyi li ọmọ Jako-
bu, ti a bí fun u ni Padanaramu.
27 Jakobu si dé ọdọ Isaaki baba rẹ̀, ni
Mamre, si Kiriat-arba, ti iṣe Hebroni,
nibiti Abrahamu ati Isaaki gbé ṣe atipo
pẹlu.
28 Ọjọ́ Isaaki si jẹ́ ọgọsan ọdún.
29 Isaaki si jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ, o si kú, a
si kó o jọ pẹlu awọn enia rẹ̀, o gbó, o si
kún fun ọjọ́, awọn ọmọ rẹ̀, Esau ati Jakobu
si sin i.

## ORI 36.

WỌNYI si ni iran Esau, ẹniti iṣe Edomu.
2 Esau fẹ́ awọn aya rẹ̀ ninu awọn
ọmọbirin Kenaani; Ada, ọmọbirin Eloni,
enia Hitti, ati Aholibama, ọmọbirin Ana,
ọmọbirin Sibeoni, ara Hiffi;
3 Ati Baṣemati, ọmọbirin Iṣmaeli, ara-
birin Nebajotu.
4 Ada si bí Elifasi fun Esau; Baṣemati
si bí Reueli;
5 Aholibama si bí Jeusi, ati Jaalamu,
ati Kora: awọn wọnyi li ọmọkọnrin Esau,
ti a bí fun u ni ilẹ Kenaani.
6 Esau si mú awọn aya rẹ̀, ati awọn
ọmọkọnrin rẹ̀, ati awọn ọmọbirin rẹ̀, ati
gbogbo awọn enia ile rẹ̀, ati ẹran rẹ̀, ati
gbogbo ohun ọ̀sin, ati ohun iní gbogbo ti
o ní ni ilẹ Kenaani; o si lọ si ilẹ kan kuro
niwaju Jakobu arakonrin rẹ̀.
7 Nitori ti ọrọ̀ wọn pọ̀ jù ki nwọn ki o
gbé pọ̀ lọ; ilẹ ti nwọn si ṣe atipo si kò le
gbà wọn, nitori ohun-ọ̀sin wọn.
8 Bẹ̃ni Esau tẹ̀dó li oke Seiri: Esau ni
Edomu.
9 Wọnyi si ni iran Esau, baba awọn ara
Edomu, li oke Seiri:
10 Wọnyi li orukọ awọn ọmọ Esau;

Digitized by Google

Elifasi ọmọ Ada, aya Esau, Rueli, ọmọ
Baṣemati, aya Esau.
11 Ati awọn ọmọ Elifasi ni Temani,
Omari, Sefo, ati Gatamu, ati Kenasi.
12 Timna li o si ṣe àle Elifasi, ọmọ
Esau; on si bí Amaleki fun Elifasi; wọnyi
si li awọn ọmọ Ada, aya Esau.
13 Wọnyi si li awọn ọmọ Reueli; Na-
hati, ati Sera, Ṣamma, ati Misa: awọn
wọnyi li awọn ọmọ Baṣemati, aya Esau.
14 Wọnyi si li awọn ọmọ Aholibama,
ọmọbirin Ana, ọmọbirin Sibeoni, aya
Esau: on si bí Jeuṣi fun Esau, ati Jaala-
mu, ati Kora.
15 Awọn wọnyi ni olori ninu awọn ọmọ
Esau; awọn ọmọ Elifasi, akọ́bi Esau; Te-
mani olori, Omari olori, Sefo olori, Kenasi
olori,
16 Kora olori, Gatamu olori, Amaleki
olori: wọnyi li awọn olori ti o ti ọdọ Eli-
fasi wá ni ilẹ Edomu, wọnyi li awọn ọmọ
Ada.
17 Wọnyi si li awọn ọmọ Reueli ọmọ
Esau; Nahati olori, Sera olori, Ṣamma
olori, Misa olori; wọnyi li awọn olori ti o
ti ọdọ Reueli wá ni ilẹ Edomu; wọnyi li
awọn ọmọ Baṣemati, aya Esau.
18 Wọnyi si li awọn ọmọ Aholibama,
aya Esau; Jeuṣi olori, Jaalamu olori, Kora
olori: wọnyi li awọn ti o ti ọdọ Aholibama
wá, aya Esau, ọmọbirin Ana.
19 Wọnyi li awọn ọmọ Esau, eyini ni
Edomu, wọnyi si li awọn olori wọn.
20 Wọnyi li awọn ọmọ Seiri, enia Hori,
ti o tẹ̀dó ni ilẹ na; Lotani, ati Ṣobali, ati
Sibeoni, ati Ana,
21 Ati Diṣoni, ati Eseri, at Diṣani:
wọnyi li awọn olori enia Hori, awọn ọmọ
Seiri ni ilẹ Edomu.
22 Ati awọn ọmọ Lotani ni Hori ati
Hemamu: arabirin Lotani si ni Timna.
23 Ati awọn ọmọ Ṣobali ni wọnyi;
Alfani, ati Mahanati, ati Ebali, Sefo, ati
Onamu.
24 Wọnyi si li awọn ọmọ Sibeoni; ati
Aja on Ana: eyi ni Ana ti o ri awọn isun
omi gbigbona ni ijù, bi o ti mbọ́ awọn kẹ-
tẹkẹtẹ Sibeoni baba rẹ̀.
25 Wọnyi si li awọn ọmọ Ana; Diṣoni
ati Aholibama, ọmọbirin Ana.
26 Wọnyi si li awọn ọmọ Diṣoni; Hem-
dani, ati Eṣbani, ati Itrani, ati Kerani.
27 Awọn ọmọ Eseri ni wọnyi; Bilhani,
ati Saafani, ati Akani.
28 Awọn ọmọ Diṣani ni wọnyi; Usi ati
Arani.
29 Wọnyi li awọn olori ti o ti ọdọ Hori
wá; Lotani olori, Ṣobali olori, Sibeoni
olori, Ana olori,
30 Diṣoni olori, Eseri olori, Diṣani olori;
wọnyi li awọn olori awọn enia Hori, ninu
awọn olori wọn ni ilẹ Seiri.
31 Wọnyi si li awọn ọba ti o jẹ ni ilẹ
Edomu, ki ọba kan ki o to jọba lori awọn
ọmọ Israeli.
32 Bela ti iṣe ọmọ Beori si jọba ni
Edomu: orukọ ilu rẹ̀ a si ma jẹ́ Dinhaba.
33 Bela si kú, Jobabu ọmọ Sera ti Bosra
si jọba ni ipò rẹ̀.
34 Jobabu si kú, Huṣamu ti ilẹ Temani
si jọba ni ipò rẹ̀.
35 Huṣamu si kú, Hadadi ọmọ Bedadi,
ẹniti o kọlù Midiani ni igbẹ́ Moabu si jọba
ni ipò rẹ̀: orukọ ilu rẹ̀ si ni Afiti.
36 Hadadi si kú, Samla ti Masreka si
jọba ni ipò rẹ̀.
37 Samla si kú, Ṣaulu ti Rehobotu leti
odò nì si jọba ni ipò rẹ̀.
38 Ṣaula si kú, Baal-hanani ọmọ Akbori
si jọba ni ipò rẹ̀.
39 Baal-hanani ọmọ Akbori si kú. Ha-
dari si jọba ni ipò rẹ̀: orukọ ilu rẹ̀ si ni
Pau; Mehetabeli si li orukọ aya rẹ̀, ọmọ-
birin Metredi, ọmọbirin Mesahabu.
40 Wọnyi si li orukọ awọn olori ti o ti
ọdọ Esau wá, gẹgẹ bi idile wọn, nipa ipò
wọn, nipa orukọ wọn; Timna olori, Aifa
olori, Jeteti olori;
41 Aholibama olori, Ela olori, Pinoni
olori.
42 Kenasi olori, Temani olori, Mibsari
olori;
43 Magdieli olori, Iramu olori: wọnyi
li awọn olori Edomu, nipa itẹ̀dó wọn ni
ilẹ iní wọn: eyi ni Esau, baba awọn ara
Edomu.

## ORI 37.

JAKOBU si joko ni ilẹ ti baba rẹ̀ ti ṣe
atipo, ani ilẹ Kenaani.
2 Wọnyi ni iran Jakobu. Nigbati
Josefu di ẹni ọdún mẹtadilogun, o nṣọ́
agbo-ẹran pẹlu awọn arakọnrin rẹ̀; ọmọde
na si wà pẹlu awọn ọmọ Bilha, ati pẹlu
awọn ọmọ Silpa, awọn aya baba rẹ̀; Josefu
si mú ihin buburu wọn wá irò fun baba
wọn.
3 Israeli si fẹ́ Josefu jù gbogbo awọn
ọmọ rẹ̀ lọ, nitori ti iṣe ọmọ ogbó rẹ̀; o si dá
ẹwu alarabara aṣọ fun u.
4 Nigbati awọn arakọnrin rẹ̀ ri pe baba
wọn fẹ́ ẹ jù gbogbo awọn arakọnrin rẹ̀ lọ

Digitized by Google

nwọn korira rẹ̀, nwọn kò si le sọ̀rọ si i li
alafia.
5 Josefu si lá alá kan, o si rọ́ ọ fun awọn
arakọnrin rẹ̀; nwọn si tun korira rẹ̀ si i.
6 O si wi fun wọn pe, Mo bẹ̀ nyin, ẹ
gbọ́ alá yi ti mo lá.
7 Sa wò o, awa nyi ití li oko, si wò o, ití
mi dide, o si duro ṣanṣan; si wò o, ití ti
nyin dide duro yika, nwọn si ntẹriba fun
ití mi.
8 Awọn arakọnrin rẹ̀ si wi fun u pe, Iwọ
o ha jọba lori wa bi? tabi iwọ o ṣe olori wa
nitõtọ? nwọn si tun korira rẹ̀ si i nitori
alá rẹ̀ ati nitori ọ̀rọ rẹ̀.
9 O si tun lá alá miran, o si rọ́ ọ fun
awọn arakọnrin rẹ̀, o wipe, Sa wò o, mo
tun lá alá kan si i; si wò o, õrùn, ati
oṣupa, ati irawọ mọkanla nforibalẹ fun
mi.
10 O si rọ́ ọ fun baba rẹ̀, ati fun awọn
arakọnrin rẹ̀: baba rẹ̀ si bá a wi, o si wi
fun u pe, Alá kili eyi ti iwọ lá yi? emi ati
iya rẹ, ati awọn arakọnrin rẹ yio ha wá
nitõtọ, lati foribalẹ fun ọ bi?
11 Awọn arakọnrin rẹ̀ si ṣe ilara rẹ̀;
ṣugbọn baba rẹ̀ pa ọ̀rọ na mọ́.
12 Awọn arakọnrin rẹ̀ si lọ lati bọ́ agbo-
ẹran baba wọn ni Ṣekemu.
13 Israeli si wi fun Josefu pe, Ni Ṣeke-
mu ki awọn arakọnrin rẹ gbé mbọ́ ẹran?
wá, emi o si rán ọ si wọn. On si wi fun u
pe, Emi niyi.
14 O si wi fun u pe, Mo bẹ̀ ọ, lọ wò ala-
fia awọn arakọnrin rẹ, ati alafia awọn agbo-
ẹran; ki o si mú ihin pada fun mi wá.
Bẹ̃li o si rán a lati afonifoji Hebroni lọ, on
si dé Ṣekemu.
15 Ọkọnrin kan si ri i, si wò o, o nrìn
kakiri ni pápa: ọkọnrin na si bi i pe, Kini
iwọ nwá?
16 On si wipe, Emi nwá awọn arakọnrin
mi: mo bẹ̀ ọ, sọ ibi ti nwọn gbé mbọ́ agbo-
ẹran wọn fun mi.
17 Ọkọnrin na si wipe, Nwọn ti lọ kuro
nihin; nitori mo gbọ́, nwọn nwipe, ẹ jẹ ki
a lọ si Dotani. Josefu si lepa awọn ara-
kọnrin rẹ̀, o si ri wọn ni Dotani.
18 Nigbati nwọn si ri i lokere; ki o tilẹ
to sunmọ eti ọdọ wọn, nwọn di rikiṣi si i
lati pa a.
19 Nwọn si wi fun ara wọn pe, Wò o,
alála nì mbọ̀wá.
20 Nisisiyi ẹ wá, ẹ jẹ ki a pa a, ki a si
wọ́ ọ sọ sinu ọkan ninu ihò wọnyi, awa o
si wipe ẹranko buburu li o pa a jẹ: awa o
si ma wò bi alá rẹ̀ yio ti ri.
21 Reubeni si gbọ́, o si gbà a li ọwọ́ wọn;
o si wipe, Ẹ máṣe jẹ ki a gbà ẹmi rẹ̀.
22 Reubeni si wi fun wọn pe, Ẹ máṣe ta
ẹ̀jẹ, ṣugbọn ẹ sọ ọ sinu ihò yi ti mbẹ li
aginjù, ki ẹ má si fọwọkàn a; nitori ki o
ba le gbà a lọwọ wọn lati mú u pada tọ̀
baba rẹ̀ lọ.
23 O si ṣe nigbati Josefu dé ọdọ awọn
arakọnrin rẹ̀, nwọn bọ́ ẹ̀wu Josefu, ẹ̀wu
alarabara aṣọ ti o wà lara rẹ̀;
24 Nwọn si mú u, nwọn si gbe e sọ sinu
ihò kan: ihò na si gbẹ, kò li omi.
25 Nwọn si joko lati jẹun: nwọn si gbé
oju wọn soke, nwọn si wò, si kiyesi i, ọwọ́-
ẹ̀ro ara Iṣmaeli nti Gileadi bọ̀; ti awọn ti
ibakasiẹ ti o rù turari ati ikunra ati ojia,
nwọn nmú wọn lọ si Egipti.
26 Judah si wi fun awọn arakọnrin rẹ̀
pe, Ere ki li o jẹ́ bi awa ba pa arakọnrin
wa, ti a si bò ẹ̀jẹ rẹ̀?
27 Ẹ wá ẹ jẹ ki a tà a fun awọn ara
Iṣmaeli ki a má si fọwọ wa kàn a; nitori
arakọnrin wa ati ara wa ni iṣe. Awọn ara-
kọnrin rẹ̀ si gbà tirẹ̀.
28 Nigbana li awọn oniṣòwo ara Midiani
nkọja lọ; nwọn si fà a, nwọn si yọ Josefu
jade ninu ihò, nwọn si tà Josefu li ogún
owo fadaka: nwọn si mú Josefu lọ si
Egipti.
29 Reubeni si pada lọ si ihò; si wò o,
Josefu kò sí ninu ihò na; o si fà aṣọ rẹ̀ ya.
30 O si pada tọ̀ awọn arakọnrin rẹ̀ lọ, o
si wipe, Ọmọde na kò sí; ati emi, nibo li
emi o gbé wọ̀?
31 Nwọn si mú ẹ̀wu Josefu, nwọn si pa
ọmọ ewurẹ kan, nwọn si rì ẹ̀wu na sinu
ẹ̀jẹ na.
32 Nwọn si fi ẹ̀wu alarabara aṣọ na ranṣẹ́,
nwọn si mú u tọ̀ baba wọn wá; nwọn si
wipe, Eyi li awa ri: mọ̀ nisisiyi bi ẹ̀wu
ọmọ rẹ ni, bi on kọ́.
33 On si mọ̀ ọ, o si wipe, Ẹwu ọmọ mi
ni; ẹranko buburu ti pa a jẹ; li aiṣe ani-
ani, a ti fà Josefu ya pẹrẹpẹrẹ.
34 Jakobu si fà aṣọ rẹ̀ ya, o si fi aṣọ ọ̀fọ
si ara rẹ̀, o si ṣọ̀fọ ọmọ rẹ̀ li ọjọ́ pupọ̀.
35 Ati gbogbo awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, ati
gbogbo awọn ọmọ rẹ̀ obirin dide lati ṣipẹ
fun u; ṣugbọn o kọ̀ lati gbipẹ̀; o si wipe,
Ninu ọ̀fọ li emi o sa sọkalẹ tọ̀ ọmọ mi lọ si
isà-okú. Bayi ni baba rẹ̀ sọkun rẹ̀.
36 Awọn ara Midiani si tà a si Egipti fun
Potifari, ijoye Farao kan, ati olori ẹṣọ́.

Digitized by Google

## ORI 38.

OSI ṣe li akokò na, ni Judah sọkalẹ lọ kuro lọdọ awọn arakọnrin rẹ̀, o si yà sọdọ ara Adullamu kan, orukọ ẹniti ijẹ́ Hira.

2 Judah si ri ọmọbirin ara Kenaani kan nibẹ̀, orukọ ẹniti ijẹ́ Ṣua; o si mú u, o si wọle tọ̀ ọ.

3 O si yún, o si bí ọmọkọnrin kan; o si sọ orukọ rẹ̀ ni Eri.

4 O si tun yún, o si bí ọmọkọnrin kan; o si sọ orukọ rẹ̀ ni Onani.

5 O si tun yún, o si bí ọmọkọnrin kan; o si sọ orukọ rẹ̀ ni Ṣela: o wà ni Kesibu, nigbati o bí i.

6 Judah si fẹ́ aya fun Eri akọ́bi rẹ̀, orukọ ẹniti ijẹ́ Tamari.

7 Eri akọ́bi Judah si ṣe enia buburu li oju OLUWA; OLUWA si pa a.

8 Judah si wi fun Onani pe, Wọle tọ̀ aya arakọnrin rẹ lọ, ki o si ṣú u li opó, ki o si bimọ si ipò arakọnrin rẹ.

9 Onani si mọ̀ pe, irú-ọmọ ki yio ṣe tirẹ̀; o si ṣe bi o ti wọle tọ̀ aya arakọnrin rẹ̀ lọ, o si dà a silẹ, ki o má ba fi irú-ọmọ fun arakọnrin rẹ̀.

10 Ohun ti o si ṣe buru loju OLUWA, nitori na li OLUWA pa a pẹlu.

11 Nigbana ni Judah wi fun Tamari aya ọmọ rẹ̀ pe, Joko li opó ni ile baba rẹ, titi Ṣela ọmọ mi o fi dàgba: nitori o wipe, Ki on má ba kú pẹlu, bi awọn arakọnrin rẹ̀. Tamari si lọ, o si joko ni ile baba rẹ̀.

12 Nigbati ọjọ́ si npẹ́, ọmọbirin Ṣua, aya Judah kú; Judah si gbipẹ̀, o si tọ̀ awọn olurẹrun agutan rẹ̀ lọ si Timnati, on ati Hira ọ̀rẹ́ rẹ̀, ara Adullamu.

13 A si wi fun Tamari pe, Kiyesi i, baba ọkọ rẹ lọ si Timnati lati rẹrun agutan rẹ̀.

14 O si bọ́ aṣọ opó rẹ̀ kuro li ara rẹ̀, o si fi iboju bò ara rẹ̀, o si roṣọ, o si joko li ẹnubode Enaimu, ti o wà li ọ̀na Timnati; nitoriti o ri pe Ṣela dàgba, a kò si fi on fun u li aya.

15 Nigbati Judah ri i, o fi i pè panṣaga; nitori o boju rẹ̀.

16 O si yà tọ̀ ọ li ẹba ọ̀na, o si wipe, Emi bẹ̀ ọ, wá na, jẹ ki emi ki o wọle tọ̀ ọ; (on kò sa mọ̀ pe aya ọmọ on ni iṣe.) On si wipe Kini iwọ o fi fun mi, ki iwọ ki o le wọle tọ̀ mi?

17 O si wipe, emi o rán ọmọ ewurẹ kan si ọ lati inu agbo wá. On si wipe, iwọ ki o fi ògo fun mi titi iwọ o fi rán a wá?

18 O si bi i pe, Ògo kili emi o fi fun ọ? on si wipe, Edidi rẹ, ati okùn rẹ, ati ọpá rẹ ti o wà li ọwọ́ rẹ; o si fi wọn fun u, o si wọle tọ̀ ọ lọ, on si ti ipa ọdọ rẹ̀ yún.

19 On si dide, o ba tirẹ̀ lọ, o si bọ́ iboju rẹ̀ lelẹ kuro lara rẹ̀, o si mú aṣọ opó rẹ̀ ró.

20 Judah si rán ọmọ ewurẹ na lati ọwọ́ ọ̀rẹ́ rẹ̀, ara Adullamu na lọ, lati gbà ògo ni wá lọwọ obirin na: ṣugbọn on kò ri i.

21 Nigbana li o bère lọwọ awọn ọkọnrin ibẹ̀ na pe, Nibo ni panṣaga nì ngbé, ti o wà ni Enaimu li ẹba ọ̀na? Nwọn si wipe, Panṣaga kan kò sí nihin.

22 O si pada tọ̀ Judah lọ, o si wipe, Emi kò ri i; ati pẹlu awọn ọkọnrin ara ibẹ̀ na wipe, Kò sí panṣaga kan nibẹ̀.

23 Judah si wipe, Jẹ ki o ma mú u fun ara rẹ̀, ki oju ki o má tì wa: kiyesi i, emi rán ọmọ ewurẹ yi, iwọ kò si ri i.

24 O si ṣe niwọ̀n oṣù mẹta lẹhin rẹ̀, ni a wi fun Judah pe, Tamari aya ọmọ rẹ ṣe àgbere; si kiyesi i pẹlu, o fi àgbere loyun. Judah si wipe, Mú u jade wá, ki a si dána sun u.

25 Nigbati a si mú u jade, o ranṣẹ si baba ọkọ rẹ̀ pe, Ọkọnrin ti o ní nkan wọnyi li emi yún fun: o si wipe, Emi bẹ̀ ọ, mọ̀ wọn, ti tani nkan wọnyi, èdidi, ati okùn, ati ọpá.

26 Judah si jẹwọ, o si wipe, O ṣe olododo jù mi lọ; nitori ti emi kò fi i fun Ṣela ọmọ mi. On kò si mọ̀ ọ mọ́ lai.

27 O si ṣe li akokò ti o nrọbí, si kiyesi i, ejirẹ́ wà ni inu rẹ̀.

28 O si ṣe nigbati o nrọbí, ti ọkan yọ ọwọ́ jade: iyãgba si mú okùn ododó o so mọ́ ọ li ọwọ́, o wipe, Eyi li o kọ jade.

29 O si ṣe, bi o ti fà ọwọ́ rẹ̀ pada, si kiyesi i, aburo rẹ̀ jade: o si wipe, Èṣe ti iwọ fi yà? yiyà yi wà li ara rẹ, nitori na li a ṣe sọ orukọ rẹ̀ ni Peresi:

30 Nikẹhin li arakọnrin rẹ̀ jade, ti o li okùn ododó li ọwọ́ rẹ̀: a si sọ orukọ rẹ̀ ni Sera.

## ORI 39.

ASI mú Josefu sọkalẹ wá si Egipti; Potifari, ijoye Farao kan, olori ẹṣọ́, ara Egipti, si rà a lọwọ awọn ara Iṣmaeli ti o mú u sọkalẹ wá sibẹ̀.

2 OLUWA si wà pẹlu Josefu, o si ṣe alasiki enia; o si wà ni ile oluwa rẹ̀ ara Egipti na.

3 Baba rẹ̀ si ri pe OLUWA pẹlu rẹ̀, ati pe, OLUWA mu ohun gbogbo ti o ṣe dara li ọwọ́ rẹ̀.

4 Josefu si ri ojurere li oju rẹ̀, on si nsìn

i: o si fi i jẹ́ olori ile rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o ní on li o fi lé e lọwọ.

5 O si ṣe lati ìgba ti o ti fi Josefu jẹ́ olori ile rẹ̀, ati olori ohun gbogbo ti o ní, ni OLUWA busi ile ara Egipti na nitori Josefu: ibukún OLUWA si wà lara ohun gbogbo ti o ní ni ile ati li oko.

6 O si fi ohun gbogbo ti o ní si ọwọ́ Josefu; kò si mọ̀ ohun ti on ní bikoṣe onjẹ ti o njẹ. Josefu si ṣe ẹni daradara ati arẹwà enia.

7 O si ṣe lẹhin nkan wọnyi, ni aya oluwa rẹ̀ gbé oju lé Josefu; o si wipe, Bá mi ṣe.

8 Ṣugbọn on kọ̀, o si wi fun aya oluwa rẹ̀ pe, kiyesi i, oluwa mi kò mọ̀ ohun ti o wà lọdọ mi ni ile, o si ti fi ohun gbogbo ti o ní lé mi lọwọ;

9 Kò sí ẹniti o pọ̀ jù mi lọ ninu ile yi; bẽni kò si pa ohun kan mọ́ kuro lọwọ mi bikoṣe iwọ, nitori pe aya rẹ̀ ni iwọ iṣe: njẹ emi o ha ti ṣe hù ìwabuburu nla yi, ki emi si dẹṣẹ si Ọlọrun?

10 O si ṣe, bi o ti nsọ fun Josefu lojojumọ́, ti on kò si gbọ́ tirẹ̀ lati dubulẹ tì i, tabi lati bá a ṣe.

11 O si ṣe niwọ̀n akokò yi, ti Josefu wọle lọ lati ṣe iṣẹ rẹ̀; ti kò si sí ẹnikan ninu awọn ọkọnrin ile ninu ile nibẹ̀.

12 On si di Josefu li aṣọ mú, o wipe, bá mi ṣe: on si jọwọ aṣọ rẹ̀ si i lọwọ, o si sá, o bọ sode.

13 O si ṣe, nigbati o ri i pe Josefu jọwọ aṣọ rẹ̀ si i lọwọ, ti o si sá jade,

14 Nigbana li o kepè awọn ọkọnrin ile rẹ̀, o si wi fun wọn pe, Ẹ wò o, o mú Heberu kan wọle tọ̀ wa wá lati fi wa ṣe ẹlẹyà; o wọle tọ̀ mi wá lati bá mi ṣe, mo si kigbe li ohùn rara:

15 O si ṣe, nigbati o gbọ́ pe mo gbé ohùn mi soke ti mo si kigbe, o jọwọ aṣọ rẹ̀ sọdọ mi, o si sá, o bọ sode.

16 O si fi aṣọ Josefu lelẹ li ẹba ọdọ rẹ̀, titi oluwa rẹ̀ fi bọ̀wá ile.

17 O si wi fun u bi ọ̀rọ wọnyi pe, Ẹrú Heberu ti iwọ mu tọ̀ wa, o wọle tọ̀ mi lati fi mi ṣe ẹlẹyà:

18 O si ṣe, bi mo ti gbé ohùn mi soke ti mo si ké, o si jọwọ aṣọ rẹ̀ sọdọ mi, o si sá jade.

19 O si ṣe, nigbati oluwa rẹ̀ gbọ́ ọ̀rọ aya rẹ̀, ti o sọ fun u wipe, Bayibayi li ẹrú rẹ ṣe si mi; o binu gidigidi.

20 Oluwa Josefu si mú u, o si fi i sinu túbu, nibiti a gbé ndè awọn ara túbu ọba; o si wà nibẹ̀ ninu túbu.

21 Ṣugbọn OLUWA wà pẹlu Josefu, o si ṣãnu fun u, o si fun u li ojurere li oju onitúbu.

22 Onitúbu si fi gbogbo awọn ara túbu ti o wà ninu túbu lé Josefu lọwọ; ohunkohun ti nwọn ba si ṣe nibẹ̀, on li oluṣe rẹ̀.

23 Onitúbu kò si bojuwò ohun kan ti o wà li ọwọ́ rẹ̀; nitori ti OLUWA wà pẹlu rẹ̀, ati ohun ti o ṣe OLUWA mú u dara.

## ORI 40.

O SI sẹ lẹhin nkan wọnyi, li agbọti ọba Egipti ati alasè rẹ̀ ṣẹ̀ ọba Egipti oluwa wọn.

2 Farao si binu si meji ninu awọn ijoye rẹ̀, si olori awọn agbọti, ati si olori awọn alasè.

3 O si fi wọn sinu túbu ninu ile olori ẹṣọ́, sinu túbu ti a gbé dè Josefu si.

4 Olori ẹṣọ́ na si fi Josefu jẹ́ olori wọn; o si nṣe itọju wọn: nwọn si pẹ diẹ ninu túbu na.

5 Awọn mejeji si lá alá kan, olukuluku lá alá tirẹ̀ li oru kanna, olukuluku bi itumọ̀ alá tirẹ̀, agbọti ati alasè ọba Egipti, ti a dè sinu túbu na.

6 Josefu si wọle tọ̀ wọn lọ li owurọ̀, o si wò wọn, si kiyesi i, nwọn fajuro.

7 O si bi awọn ijoye Farao ti o wà pẹlu rẹ̀ ninu ile túbu oluwa rẹ̀ pe, Ẽṣe ti oju nyin fi buru bẽ loni?

8 Nwọn si wi fun u pe, Awa lá alá kò si sí onitumọ̀ rẹ̀. Josefu si wi fun wọn pe, Ti Ọlọrun ki itumọ̀ iṣe ndan? emi bẹ̀ nyin, ẹ rọ́ wọn fun mi.

9 Olori agbọti si rọ́ alá tirẹ̀ fun Josefu, o si wi fun u pe, Li oju alá mi, kiyesi i, àjara kan wà niwaju mi,

10 Ati lara àjara na li ẹka mẹta wà; o si rudi, itana rẹ̀ si tú jade; ati ṣiri rẹ̀ si so eso-àjara ti o pọ́n.

11 Ago Farao si wà li ọwọ́ mi: emi si mú eso-àjara na, mo si fún wọn sinu ago Farao, mo si fi ago na lé Farao lọwọ.

12 Josefu si wi fun u pe, Itumọ̀ rẹ̀ li eyi: ẹka mẹta nì, ijọ́ mẹta ni:

13 Ni ijọ́ mẹta oni, ni Farao yio gbe ori rẹ soke yio si mú ọ pada si ipò rẹ: iwọ o si fi ago lé Farao li ọwọ́ gẹgẹ bi ti ìgba iṣaju nigbati iwọ ti ṣe agbọti rẹ̀.

14 Ṣugbọn ki o ranti mi nigbati o ba dara fun ọ, ki o si fi iṣeun rẹ hàn fun mi, emi bẹ̀ ọ, ki o si da orukọ mi fun Farao, ki o si mú mi jade ninu ile yi.

15 Nitõtọ jíji li a jí mi tà lati ilẹ awọn

Heberu wá: ati nihinyi pẹlu, emi kò ṣe nkan ti nwọn fi fi mi sinu ihò túbu yi.

16 Nigbati olori alasè ri pe itumọ̀ alá na dara, o si wi fun Josefu pe, Emi wà li oju-alá mi pẹlu, si kiyesi i, emi rù agbọ̀n àkara funfun mẹta li ori mi:

17 Ati ninu agbọ̀n ti o wà loke li onirũru onjẹ sisè wà fun Farao; awọn ẹiyẹ si njẹ ẹ ninu agbọ̀n na ti o wà li ori mi.

18 Josefu si dahùn o si wipe, itumọ̀ rẹ̀ li eyi: agbọ̀n mẹta nì, ijọ́ mẹta ni.

19 Ni ijọ́ mẹta oni ni Farao yio gbé ori rẹ kuro lara rẹ, yio si so ọ rọ̀ lori igi kan; awọn ẹiyẹ yio si ma jẹ ẹran ara rẹ kuro lara rẹ.

20 O si ṣe ni ijọ́ kẹta, ti iṣe ọjọ́ ibí Farao, ti o sè àse fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ gbogbo: o si gbé ori olori agbọti soke ati ti olori awọn alasè lãrin awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀.

21 O si tun mú olori agbọti pada si ipò rẹ̀; on si fi ago lé Farao li ọwọ́:

22 Ṣugbọn olori alasè li o sorọ̀: bi Josefu ti tumọ̀ alá na fun wọn.

23 Ṣugbọn olori agbọti kò ranti Josefu, o gbagbe rẹ̀.

## ORI 41.

O SI ṣe li opin ọdún meji ṣánṣan, ni Farao lá alá: si kiyesi i, o duro li ẹba odo.

2 Si kiyesi i abo-malu meje, ti o dara ni wiwò, ti o sanra, jade lati inu odò na wá: nwọn si njẹ ninu ẽsu-odò.

3 Si kiyesi i, abo-malu meje miran ti o buru ni wiwò, ti o si rù, jade lẹhin wọn lati inu odò na wá; nwọn si duro tì awọn abo-malu nì ni bèbe odò na.

4 Awọn abo-malu ti o buru ni wiwò ti o si rù si mú awọn abo-malu meje ti o dara ni wiwò ti o si sanra wọnni jẹ. Bẽni Farao jí.

5 O si sùn, o si lá alá lẹrinkeji: si kiyesi i, ṣiri ọkà meje yọ lara igi ọkà kan, ti o kún ti o si dara.

6 Si kiyesi i, ṣiri ọkà meje ti o fori ti afẹfẹ ìla-õrùn rẹ̀ dànu si rú jade lẹhin wọn.

7 Ṣiri meje ti o fori si mú ṣiri meje daradara ti o kún nì jẹ. Farao si jí, si kiyesi i, alá ni.

8 O si ṣe li owurọ̀, ti ọkàn rẹ̀ kò lelẹ; o si ranṣẹ o si pè gbogbo awọn amoye Egipti, ati gbogbo awọn ọ̀mọran ibẹ̀ wá; Farao si rọ́ alá rẹ̀ fun wọn: ṣugbon kò sí ẹnikan ti o le tumọ wọn fun Farao.

9 Nigbana li olori agbọti wi fun Farao pe, Emi ranti ẹ̀ṣẹ mi loni:

10 Farao binu si awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀, o si fi mi sinu túbu ni ile-túbu olori ẹṣọ́, emi ati olori alasè:

11 Awa si lá alá li oru kanna, emi ati on; awa lá alá olukuluku bi itumọ̀ alá tirẹ̀.

12 Ọdọmọkọnrin kan ara Heberu, ọmọ-ọdọ olori ẹṣọ́, si wà nibẹ̀ pẹlu wa; awa si rọ́ wọn fun u, o si tumọ̀ alá wa fun wa, o tumọ̀ fun olukuluku gẹgẹ bi alá tirẹ̀.

13 O si ṣe bi o ti tumọ̀ fun wa, bẹ̃li o si ri; emi li o mú pada si ipò iṣẹ mi, on li o si sorọ̀.

14 Nigbana ni Farao ranṣẹ o si pè Josefu, nwọn si yara mú u jade kuro ninu ihò-túbu; o si fari rẹ̀, o si parọ̀ aṣọ rẹ̀, o si tọ̀ Farao wá.

15 Farao sí wi fun Josefu pe, Emi lá alá, kò si si ẹnikan ti o le tumọ̀ rẹ̀: emi si gburó rẹ pe, bi iwọ ba gbọ́ alá, iwọ le tumọ̀ rẹ̀.

16 Josefu si da Farao li ohùn pe, Ki iṣe emi: Ọlọrun ni yio fi idahùn alafia fun Farao.

17 Farao si wi fun Josefu pe, Li oju-alá mi, kiyesi i, emi duro lori bèbe odò.

18 Si kiyesi i, abo-malu meje ti o sanra, ti o si dara lati wò, jade lati inu odò na wa; nwọn si njẹ ni ẽsu-odò:

19 Si kiyesi i, abo-malu meje miran ti o joro, ti o burujù ni wiwò ti o si rù, jade soke lẹhin wọn, nwọn buru tobẹ̃ ti emi kò ri irú wọn rí ni ilẹ Egipti.

20 Awọn abo-malu ti o rù, ti nwọn si buru ni wiwò, nwọn mú awọn abo-malu meje sisanra iṣaju wọnni jẹ:

21 Nigbati nwọn si jẹ wọn tán, a kò le mọ̀ pe, nwọn ti jẹ wọn: nwọn si buru ni wiwò sibẹ̀ gẹgẹ bi ìgba iṣaju. Bẹ̃ni mo jí.

22 Mo si ri li oju-alá mi, si kiyesi i, ṣiri ọkà meje jade lara igi ọkà kan, o kún o si dara:

23 Si kiyesi i, ṣiri ọkà meje rirẹ̀, ti o si fori, ati ti ẹfũfu ìla-õrùn rẹ̀ dànu, o rú jade lẹhin wọn:

24 Awọn ṣiri ti o fori si mú awọn ṣiri rere meje nì jẹ: mo si rọ́ ọ fun awọn amoye; ṣugbọn kò sí ẹniti o le sọ ọ fun mi.

25 Josefu si wi fun Farao pe, Ọkan li alá Farao: Ọlọrun ti fi ohun ti on mbọ̀wá iṣe hàn fun Farao.

26 Awọn abo-malu daradara meje nì, ọdún meje ni: ati ṣiri daradara meje nì, ọdún meje ni: ọkan li alá na.

27 Ati awọn abo-malu meje nì ti o rù ti o si buru ni wiwò ti nwọn jade soke lẹhin

Digitized by Google

wọn, ọdún meje ni; ati şiri ọkà meje ti o
fori nì, ti ẹfũfu ìla-õrùn rẹ̀ dànu nì, ọdún
meje ìyan ni yio jasi.
28 Eyi li ohun ti mo ti wi fun Farao pe,
ohun ti Ọlọrun mbọ̀wá işe, o ti fihàn fun
Farao.
29 Kiyesi i, ọdún meje ọ̀pọ mbọ̀, já gbo-
gbo ilẹ Egipti:
30 Lẹhin wọn ọdún meje ìyan si mbọ̀;
gbogbo ọ̀pọ nì li a o si gbagbe ni ilẹ Egipti;
ìyan na yio si run ilẹ;
31 A ki yio si mọ̀ ọ̀pọ na mọ́ ni ilẹ
nitori ìyan na ti yio tẹle e, nitori yio mú
gidigidi.
32 Nitorina li alá na şe dìlu ni meji fun
Farao; nitoripe lati ọdọ Ọlọrun li a ti fi idi
ọ̀ran na mulẹ, Ọlọrun yio si mú u şẹ kán-
kan.
33 Njẹ nisisiyi, ki Farao ki o wò amoye
ati ọlọgbọ́n ọkọnrin kan, ki o si fi i şe olori
ilẹ Egipti.
34 Ki Farao ki o şe eyi, ki o si yàn
awọn alabojuto si ilẹ yi, ki nwọn ki o si
gbà idamarun ni ilẹ Egipti li ọdún meje
ọ̀pọ nì.
35 Ki nwọn ki o si kó gbogbo onjẹ ọdún
meje rere nì ti o dé, ki nwọn ki o si tò ọkà
jọ si ọwọ́ Farao, ki nwọn ki o si pa onjẹ mọ́
ni ilu wọnni.
36 Onjẹ na ni yio si şe isigbẹ fun ilẹ dè
ọdún meje ìyan na, ti mbọ̀wà si ilẹ Egipti;
ki ilẹ ki o má ba run nitori ìyan na.
37 Ohun na si dara li oju Farao, ati li
oju gbogbo awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀.
38 Farao si wi fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ pe,
A ha le ri ẹnikan bi irú eyi, okọnrin ti
Emi Ọlọrun mbẹ ninu rẹ̀?
39 Farao si wi fun Josefu pe, Niwọnbi
Ọlọrun ti fi gbogbo nkan yi hàn ọ, kò sí
ẹniti o şe amoye ati ọlọgbọ́n bi iwọ:
40 Iwọ ni yio şe olori ile mi, gẹgẹ bi ọ̀rọ
rẹ li a o si ma şe akoso awọn enia mi: itẹ́
li emi o fi tobi jù ọ lọ:
41 Farao si wi fun Josefu pe, Wò o, emi
fi ọ jẹ́ olori gbogbo ilẹ Egipti.
42 Farao si bọ́ oruka ọwọ́ rẹ̀ kuro, o si fi
bọ̀ Josefu li ọwọ́, o si wọ̀ ọ li aşọ ọ̀gbọ dara-
dara, o si fi ẹ̀wọn wurà si i li ọrùn;
43 O si mu u gùn kẹkẹ́ keji ti o ní; nwọn
si nké niwaju rẹ̀ pe, Kabiyesi: o si fi i jẹ́
olori gbogbo ilẹ Egipti.
44 Farao si wi fun Josefu pe, Emi ni
Farao, lẹhin rẹ ẹnikeni kò gbọdọ gbé ọwọ́
tabi ẹsẹ̀ soke ni gbogbo ilẹ Egipti.
45 Farao si sọ orukọ Josefu ni Safnati-
paanea; o si fi Asenati fun u li aya, ọmọ-
birin Potifera, alufa Oni. Josefu si jade lọ
si ori ilẹ Egipti.
46 Josefu si jẹ́ ẹni ọgbọ̀n ọdún nigbati o
duro niwaju Farao ọba Egipti. Josefu si
jade kuro niwaju Farao, o si là gbogbo ilẹ
Egipti já.
47 Li ọdún meje ọ̀pọ nì, ilẹ so eso ni
ikunwọ-ikunwọ.
48 O si kó gbogbo onjẹ ọdún meje nì jọ,
ti o wà ni ilẹ Egipti, o si fi onjẹ na şura ni
ilu wọnni: onjẹ oko ilu ti o yi i ká, on li o
kójọ sinu rẹ̀.
49 Josefu si kó ọkà jọ bi iyanrin okun
lọ̀pọlọpọ; titi o fi dẹkun ati mã şirò; nito-
ri ti kò ní iye.
50 A si bí ọmọkọnrin meji fun Josefu,
ki ọdún ìyan na ki o to dé, ti Asenati bí
fun u, ọmọbirin Potifera, alufa Oni.
51 Josefu si sọ orukọ akọ́bi ni Manasse:
wipe, Nitori ti Ọlọrun mu mi gbagbe gbo-
gbo işẹ́ mi, ati gbogbo ile baba mi.
52 Orukọ ekeji li o si sọ ni Efraimu:
nitori Ọlọrun ti mu mi bisi i ni ilẹ ipọnju
mi.
53 Ọdún meje ọ̀pọ na ti o wà ni ilẹ
Egipti si pari.
54 Ọdún meje ìyan si bẹ̀rẹ si dé, gẹgẹ bi
Josefu ti wi: ìyan na si mú ni ilẹ gbogbo;
şugbọn ni gbogbo ilẹ Egipti li onjẹ gbé wà.
55 Nigbati ìyan mú ni gbogbo ilẹ Egipti,
awọn enia kigbe onjẹ tọ̀ Farao: Farao si
wi fun gbogbo awọn ara Egipti pe, Ẹ ma
tọ̀ Josefu lọ; ohunkohun ti o ba wi fun
nyin ki ẹ şe.
56 Iyan na si wà lori ilẹ gbogbo: Josefu
si şí gbogbo ile işura silẹ, o si ntà fun awọn
ara Egipti; ìyan na si nmú si i ni lẹ Egipti.
57 Ilẹ gbogbo li o si wá si Egipti lati rà
onjẹ lọdọ Josefu; nitori ti ìyan na mú
gidigidi ni ilẹ gbogbo.

## ORI 42.

NIGBATI Jakobu si ri pe ọkà wà ni
Egipti, Jakobu wi fun awọn ọmọ rẹ̀,
pe, Eşe ti ẹnyin fi nwò ara nyin li oju?
2 O si wipe, Wò o, mo gbọ́ pe ọkà mbẹ
ni Egipti: ẹ sọkalẹ lọ sibẹ̀, ki ẹ si rà fun
wa lati ibẹ̀ wá; ki awa ki o le yè, ki a
máşe kú.
3 Awọn arakọnrin Josefu mẹwẹwa si sọ-
kalẹ lọ lati rà ọkà ni Egipti.
4 Şugbọn Jakobu kò rán Benjamini ara-
kọnrin Josefu pẹlu awọn arakọnrin rẹ̀;
nitori ti o wipe, ki ibi ki o má ba bá a.
5 Awọn ọmọ Israeli si wá irà ọkà ninu



Digitized by Google

awọn ti o wá: nitori ìyan na mú ni ilẹ
Kenaani.
6 Josefu li o si ṣe balẹ ilẹ na, on li o ntà
fun gbogbo awọn enia ilẹ na; awọn arakọn-
rin Josefu si wá, nwọn si tẹ̀ ori wọn ba
fun u, nwọn dojubolẹ.
7 Josefu si ri awọn arakọnrin rẹ̀, o si
mọ̀ wọn, ṣugbọn o fi ara rẹ̀ ṣe àjeji fun wọn,
o si sọ̀rọ akọ si wọn: o si wi fun wọn pe,
Nibo li ẹnyin ti wá? nwọn si wipe, Lati
ilẹ Kenaani lati rà onjẹ.
8 Josefu si mọ̀ awọn arakọnrin rẹ̀, ṣu-
gbọn awọn kò mọ̀ ọ.
9 Josefu si ranti alá wọnni ti o ti lá si
wọn, o si wi fun wọn pe, Amí li ẹnyin;
lati ri ìhoho ilẹ yi li ẹnyin ṣe wá.
10 Nwọn si wi fun u pe, Bẽkọ, oluwa
mi, ṣugbọn lati rà onjẹ li awọn iranṣẹ rẹ ṣe
wá.
11 Ọmọ ẹnikan na ni gbogbo wa iṣe;
olõtọ enia li awa, awa iranṣẹ rẹ ki iṣe amí.
12 O si wi fun wọn pe, Bẽkọ, ṣugbọn
lati ri ìhoho ilẹ li ẹ ṣe wá.
13 Nwọn si wipe, Arakọnrin mejila li
awa iranṣẹ rẹ, ọmọ ẹnikan na ni ilẹ Kena-
ani: si wò o, eyi abikẹhin si wà lọdọ baba
wa loni-oloni, ọkan kò si sí.
14 Josefu si wi fun wọn pe, On na li
eyiti mo wi fun nyin pe, Amí li ẹnyin:
15 Eyi bayi li a o fi ridi nyin, ẹmi Farao
bi ẹnyin o ti lọ nihin bikoṣepe arakọnrin
abikẹhin nyin wá ihinyi.
16 Ẹ rán ẹnikan ninu nyin, ki o si mú
arakọnrin nyin wá, a o si pa nyin mọ ninu
tubu, ki a le ridi ọ̀rọ nyin, bi otitọ wà
ninu nyin: bikoṣe bẽ, ẹmi Farao bi amí ki
ẹnyin iṣe.
17 O si kó gbogbo wọn pọ̀ sinu túbu ni
ijọ́ mẹta.
18 Josefu si wi fun wọn ni ijọ́ kẹta pe,
Ẹ ṣe eyi ki ẹ si yè; nitori emi bẹ̀ru Ọlọrun.
19 Bi ẹnyin ba ṣe olõtọ enia, ki a mú
ọkan ninu awọn arakọnrin nyin dè ni ile
túbu nyin: ẹ lọ ẹ mú okà lọ nitori ìyan ile
nyin.
20 Ṣugbọn ẹ mú arakọnrin nyin abikẹ-
hin fun mi wá; bẽli a o si mọ̀ ọ̀rọ nyin li
otitọ, ẹ ki yio si kú. Nwọn si ṣe bẽ.
21 Nwọn si wi fun ara wọn pe, Awa jẹbi
nitõtọ nipa ti arakọnrin wa, niti pe, a ri
àrokan ọkàn rẹ̀, nigbati o bẹ̀ wa, awa kò si
fẹ́ igbọ́; nitorina ni iyọnu yi ṣe bá wa.
22 Reubeni si da wọn li ohùn pe, Emi
kò wi fun nyin pe, Ẹ máṣe ṣẹ̀ si ọmọde na;
ẹ kò si fẹ̀ igbọ́? si wò o, nisisiyi, a mbère
ẹ̀jẹ rẹ̀.
23 Nwọn kò si mọ̀ pe Josefu gbédè wọn;
nitori gbedegbẹyọ li o fi mba wọn sọ̀rọ.
24 O si yipada kuro lọdọ wọn, o si sọ-
kun; o si tun pada tọ̀ wọn wá, o si bá wọn
sọ̀rọ, o si mú Simeoni ninu wọn, o si dè e
li oju wọn.
25 Nigbana ni Josefu paṣẹ ki nwọn fi ọkà
kún inu àpo wọn, ki nwọn si mú owo olu-
kuluku pada sinu àpo rẹ̀, ki nwọn ki o si
fun wọn li onjẹ ọ̀na; bayi li o si ṣe fun
wọn.
26 Nwọn si dì ọkà lé kẹtẹkẹtẹ wọn,
nwọn si lọ kuro nibẹ̀.
27 Bi ọkan ninu wọn si ti tú àpo rẹ̀ ni
ile-èro lati fun kẹtẹkẹtẹ rẹ̀ li onjẹ, o kofiri
owo rẹ̀; si wò o, o wà li ẹnu àpo rẹ̀.
28 O si wi fun awọn arakọnrin rẹ̀ pe,
Nwọn mú owo mi pada; si wò o, o tilẹ wà
li àpo mi: àiya si fò wọn, ẹ̀ru si bà wọn,
nwọn nwi fun ara wọn pe, Kili eyiti Ọlọrun
ṣe si wa yi?
29 Nwọn si dé ọdọ Jakobu baba wọn ni
ilẹ Kenaani, nwọn si ròhin ohun gbogbo
ti o bá wọn fun u wipe,
30 Ọkọnrin na ti iṣe oluwa ilẹ na, sọ̀rọ
lile si wa, o si fi wa pè amí ilẹ na.
31 A si wi fun u pe, Olõtọ enia li awa;
awa ki iṣe amí:
32 Arakọnrin mejila li awa, ọmọ baba
wa; ọkan kò sí, abikẹhin si wà lọdọ baba
wa ni ilẹ Kenaani loni-oloni.
33 Ọkọnrin na, oluwa ilẹ na, si wi fun
wa pe, Nipa eyi li emi o fi mọ̀ pe olõtọ
enia li ẹnyin; ẹ fi ọkan ninu awọn arakọn-
rin nyin silẹ lọdọ mi, ki ẹ si mú onjẹ
nitori ìyan ile nyin, ki ẹ si ma lọ.
34 Ẹ si mú arakọnrin nyin abikẹhin nì
tọ̀ mi wá: nigbana li emi o mọ̀ pe ẹnyin
ki iṣe amí, bikoṣe olõtọ enia: emi o si fi
arakọnrin nyin lé nyin lọwọ, ẹnyin o si ma
ṣòwo ni ilẹ yi.
35 O si ṣe, bi nwọn ti ndà àpo wọn, wò
o, ìdi owo olukuluku wà ninu àpo rẹ̀: ni-
gbati awọn ati baba wọn si ri ìdi owo
wọnni, ẹ̀ru bà wọn.
36 Jakobu baba wọn si wi fun wọn pe,
Emi li ẹnyin gbà li ọmọ: Josefu kò sí;
Simeoni kò si sí; ẹ si nfẹ́ mú Benjamini
lọ: lara mi ni gbogbo nkan wọnyi pọ̀ si.
37 Reubeni si wi fun baba rẹ̀ pe, Pa
ọmọ mi mejeji bi emi kò ba mú u fun ọ
wá: fi i lé mi lọwọ, emi o si mú u pada
fun ọ wá.
38 On si wipe, Ọmọ mi ki yio bá nyin
sọkalẹ lọ; nitori arakọnrin rẹ̀ ti kú, on
nikan li o si kù: bi ibi ba bá a li ọ̀na ti

Digitized by Google

ẹnyin nlọ, nigbana li ẹnyin o fi ibinujẹ mú
ewú mi lọ si isà-okú.

## ORI 43.

IYAN na si mú ni ilẹ na gidigidi.
2 O si ṣe, nigbati nwọn jẹ ọkà ti nwọn
ti múbọ̀ Egipti wá tán, baba wọn wi fun
wọn pe, Ẹ tun lọ irà onjẹ diẹ fun wa wá.
3 Judah si wi fun u pe, Ọkọnrin na tẹ-
numọ́ ọ gidigidi fun wa pe, Ẹnyin kò gbọdọ
ri oju mi, bikoṣepe arakọnrin nyin ba pẹlu
nyin.
4 Bi iwọ o ba rán arakọnrin wa pẹlu wa,
awa o sọkalẹ lọ lati rà onjẹ fun ọ:
5 Ṣugbọn bi iwọ ki yio ba rán a, awa ki
yio sọkalẹ lọ: nitoriti ọkọnrin na wi fun
wa pe, Ẹnyin ki yio ri oju mi, bikoṣe ara-
kọnrin nyin ba pẹlu nyin.
6 Israeli si wipe, Ẽṣe ti ẹnyin fi hùwabu-
buru bẽ̀ si mi, ti ẹnyin fi wi fun ọkọnrin na
pe, ẹnyin ní arakọnrin kan pẹlu?
7 Nwọn si wipe, Ọkọnrin na bère timọ-
timọ niti awa tikara wa, ati niti ibatan wa,
wipe, Baba nyin wà sibẹ̀? ẹnyin li ara-
kọnrin miran? awa si wi fun u bi ọ̀rọ
wọnyi: awa o ti ṣe le mọ̀ daju pe yio wipe,
Mú arakọnrin nyin sọkalẹ wá?
8 Judah si wi fun Israeli baba rẹ̀ pe,
Rán ọdọmọde na ba mi lọ, awa o si dide, a
o lọ; ki awa ki o le yè, ki a má si ṣe kú,
ati awa ati iwọ, ati awọn ọmọ wẹrẹ wa.
9 Emi ni yio ṣe onigbọwọ rẹ̀: li ọwọ́ mi
ni iwọ o bère rẹ̀; bi emi kò ba mú u pada
fun ọ wá, ki nsi mu u duro niwaju rẹ, njẹ
emi ni yio rù ẹbi na lailai.
10 Bikoṣepe bi awa ti nṣe ilọra, awa iba
sa ti pada bọ̀ lẹrinkeji nisisiyi.
11 Israeli baba wọn si wi fun wọn pe,
Njẹ bi bẽ̀ ba ni, eyi ni ki ẹ ṣe, ẹ mú ninu
ãyo eso ilẹ yi, sinu ohun-èlo nyin, ki ẹ si
mú ọrẹ lọ fun ọkọnrin na, ikunra diẹ, ati
oyin diẹ, ati turari, ojia, eso pupa, ati eso
almondi:
12 Ki ẹ si mú owo miran li ọwọ́ nyin;
ati owo ti a mú pada wá li ẹnu àpo nyin, ẹ
si tun mú u li ọwọ̀ lọ; bọya o le ṣe èṣi:
13 Ẹ mú arakọnrin nyin pẹlu, ẹ si dide,
ẹ tun pada tọ̀ ọkọnrin na lọ:
14 Ki Ọlọrun Olodumare ki o si fun nyin
li ãnu niwaju ọkọnrin na, ki o le rán ara-
kọnrin nyin ọhún wá, ati Benjamini. Bi
a ba gbà mi li ọmọ, a gbà mi li ọmọ.
15 Awọn ọkọnrin na si mú ọrẹ na, nwọn
si mú iṣẹ́po owo meji li ọwọ́ wọn, ati Ben-
jamini; nwọn si dide, nwọn si sọkalẹ lọ si
Egipti, nwọn si duro niwaju Josefu.
16 Nigbati Josefu si ri Benjamini pẹlu
wọn, o wi fun olori ile rẹ̀ pe, Mú awọn
ọkọnrin wọnyi rè ile, ki o si pa ẹran, ki o
si pèse: nitori ti awọn ọkọnrin wọnyi yio
ba mi jẹun li ọjọkanri.
17 Ọkọnrin na si ṣe bi Josefu ti wi;
ọkọnrin na si mú awọn ọkọnrin na lọ si ile
Josefu.
18 Awọn ọkọnrin na si mbẹ̀ru, nitori ti
a mú wọn wá si ile Josefu; nwọn si wipe,
Nitori owo ti a mú pada sinu àpo wa li
akọ́wa li a ṣe mú wa wọle; ki o le fẹ wa
lẹfẹ, ki o si le kọlù wa, ki o si le kó wa ṣe
ẹrú ati awọn kẹtẹkẹtẹ wa.
19 Nwọn si sunmọ iriju ile Josefu, nwọn
si bá a sọ̀rọ li ẹnu-ọ̀na ile na,
20 Nwọn si wipe, Alagba, nitõtọ li awa
sọkalẹ wá ni iṣaju lati rà onjẹ:
21 O si ṣe, nigbati awa dé ile-èro, ti awa
tú àpo wa, si kiyesi i, owo olukuluku wà li
ẹnu àpo rẹ̀, owo wa ni pípe ṣánṣan: awa si
tun mú u li ọwọ́ pada wá.
22 Owo miran li awa si mú li ọwọ́ wa
sọkalẹ wá lati rà onjẹ: awa kò mọ̀ ẹniti o
fi owo wa sinu àpo wa.
23 O si wi fun wọn pe, Alafia ni fun
nyin, ẹ má bẹ̀ru: Ọlọrun nyin ati Ọlọrun
baba nyin, li o fun nyin ni iṣura ninu àpo
nyin: owo nyin dé ọwọ́ mi. O si mú
Simeoni jade tọ̀ wọn wá.
24 Ọkọnrin na si mú awọn ọkọnrin na
wá si ile Josefu, o si fun wọn li omi, nwọn
si wẹ̀ ẹsẹ̀ wọn; o si fun awọn kẹtẹkẹte wọn
li ohun jijẹ.
25 Nwọn si ti mú ọrẹ na silẹ dè atibọ̀
Josefu lọsán: nitoriti nwọn gbọ́ pe nwọn
o jẹun nibẹ̀.
26 Nigbati Josefu si bọ̀wá ile, nwọn si
mú ọrẹ ti o wà li ọwọ́ wọn fun u wá sinu
ile, nwọn si tẹriba fun u ni ilẹ.
27 On si bère alafia wọn, o si wipe, Alafia
ki baba nyin wà, arugbo na ti ẹnyin wi? o
wà lãye sibẹ̀?
28 Nwọn si dahun pe, Ara baba wa,
iranṣẹ rẹ le, o wà sibẹ̀. Nwọn si tẹri wọn
ba, nwọn si bù ọlá fun u.
29 O si gbé oju rẹ̀ soke, o si ri Ben-
jamini, aburo rẹ̀, ọmọ iya rẹ̀, o si wipe,
Abikẹhin nyin na ti ẹnyin wi fun mi li
eyi? o si wipe, Ki Ọlọrun ki o ṣe ojurere si
ọ, ọmọ mi.
30 Josefu si yara; nitori ti inu yọ́ ọ si
aburo rẹ̀: o wá ibi ti yio gbé sọkun; o si
bọ́ si iyẹwu, o si sọkun nibẹ̀.
31 O si bọju rẹ̀, o si jade; o si mú oju
dá, o si wipe, Ẹ gbé onjẹ kalẹ.

Digitized by Google

32 Nwọn si gbé tirẹ̀ kalẹ fun u lọtọ̀, ati
fun wọn lọtọ̀, ati fun awọn ara Egipti ti o
mbá a jẹun lọtọ̀; nitori ti awọn ara Egipti
kò gbọdọ bá awọn enia Heberu jẹun; nitori
irira ni fun awọn ara Egipti.
33 Nwọn si joko niwaju rẹ̀, akọ́bi gẹgẹ
bi ipò ibí rẹ̀, ati abikẹhin gẹgẹ bi ipò ewe
rẹ̀: ẹnu si yà awọn ọkọnrin na si ara
wọn.
34 O si bù onjẹ fun wọn lati iwaju rẹ̀ lọ:
ṣugbọn onjẹ Benjamini jù ti ẹnikẹni wọn
lẹrinmarun. Nwọn si mu, nwọn si bá a ṣe
ariya.

## ORI 44.

O SI fi aṣẹ fun iriju ile rẹ̀, wipe, Fi onjẹ
kún inu àpo awọn ọkọnrin wọnyi, ìwọn
ti nwọn ba le rù, ki o si fi owo olukuluku
si ẹnu àpo rẹ̀.
2 Ki o si fi ago mi, ago fadaka nì, si ẹnu
àpo abikẹhin, ati owo ọkà rẹ̀. O si ṣe gẹgẹ
bi ọ̀rọ ti Josefu ti sọ.
3 Bi ojúmọ ṣi ti mọ́, a si rán awọn ọkọn-
rin na lọ, awọn ati awọn kẹtẹkẹtẹ wọn.
4 Nigbati nwọn si jade kuro ni ilu na,
ti nwọn kò si jìna, Josefu wi fun iriju rẹ̀
pe, Dide, lepa awọn ọkọnrin na; nigbati
iwọ ba si bá wọn, wi fun wọn pe, Ẽṣe ti
ẹnyin fi fi buburu san rere?
5 Ninu eyi ki oluwa mi ima mu, eyiti o
si fi nmọ̀ran? ẹnyin ṣe buburu li eyiti ẹnyin
ṣe yi.
6 O si lé wọn bá, o si sọ ọ̀rọ wọnyi fun
wọn.
7 Nwọn si wi fun u pe, Ẽṣe ti oluwa mi
fi sọ irú ọ̀rọ wọnyi? Ki a má ri pe awọn
ọmọ-ọdọ rẹ ṣe bi irú nkan wọnyi.
8 Kiyesi i, owo ti awa ri li ẹnu àpo wa,
awa si tun mú pada fun ọ lati ilẹ Kenaani
wá: bawo li awa o ṣe jí fadaka tabi wurà
ninu ile oluwa rẹ?
9 Lọdọ ẹnikẹni ninu awọn iranṣẹ rẹ ti a
ba ri i, ki o kú, ati awa pẹlu ki a di ẹrú
oluwa mi.
10 O si wipe, Njẹ ki o si ri bẽ gẹgẹ bi
ọ̀rọ nyin: ẹniti a ba ri i li ọwọ́ rẹ̀ on ni yio
di ẹrú mi, ẹnyin o si ṣe alailẹṣẹ.
11 Nigbana ni olukuluku nwọn yara sọ̀
àpo rẹ̀ kalẹ, olukuluku uwọn si tú àpo rẹ̀.
12 O si nwá a kiri, o bẹ̀rẹ lati ẹgbọ́n wá,
o si pin lọdọ abikẹhin: a si ri ago na ninu
àpo Benjamini.
13 Nigbana ni nwọn fà aṣọ wọn ya olu-
kuluku si dì ẹrù lé kẹtẹkẹtẹ rẹ̀, nwọn si
pada lọ si ilu.
14 Ati Judah ati awọn arakọnrin rẹ̀ wá
si ile Josefu; on sa wà nibẹ̀: nwọn si wolẹ̀
niwaju rẹ̀.
15 Josefu si wi fun wọn pe, Iwa kili
eyiti ẹnyin hù yi? ẹnyin kò mọ̀ pe irú enia
bi emi a ma mọ̀ran nitõtọ?
16 Judah si wipe, Kili a o wi fun oluwa
mi? kili a o fọ̀? tabi awa o ti ṣe wẹ̀ ara wa
mọ́? Ọlọrun ti hú ẹ̀ṣẹ awọn iranṣẹ rẹ jade:
wò o, awa di ẹrú oluwa mi, ati awa, ati
ẹniti a ri ago na li ọwọ́ rẹ̀ pẹlu.
17 On si wipe, Ki a má ri pe emi o ṣe
bẽ: ṣugbọn ọkọnrin na li ọwọ́ ẹniti a ri ago
na, on ni yio ṣe ẹrú mi; bi o ṣe ti ẹnyin, ẹ
goke tọ̀ baba nyin lọ li alafia.
18 Nigbana ni Judah sunmọ ọdọ rẹ̀, o si
wipe, Oluwa mi, emi bẹ̀ ọ, jẹ ki iranṣẹ rẹ
ki o sọ gbolohùn ọ̀rọ kan li eti oluwa mi,
ki o máṣe binu si iranṣẹ rẹ; bi Farao
tikalarẹ̀ ni iwọ sá ri.
19 Oluwa mi bère lọwọ awọn iranṣẹ rẹ̀,
wipe, Ẹnyin ní baba, tabi arakọnrin bi?
20 Awa si wi fun oluwa mi pe, Awa ní
baba, arugbo, ati ọmọ kan li ogbo-logbo rẹ̀,
abikẹhin; arakọnrin rẹ̀ si kú, on nikanṣoṣo
li o si kù li ọmọ iya rẹ̀, baba rẹ̀ si fẹ́ ẹ.
21 Iwọ si wi fun awọn iranṣẹ rẹ pe, Mú
u sọkalẹ tọ̀ mi wá, ki emi ki o le fi oju mi
kàn a.
22 Awa si wi fun oluwa mi pe, Ọdọmọde
na kò le fi baba rẹ̀ silẹ: nitoripe bi o ba fi
i silẹ, baba rẹ̀ yio kú.
23 Iwọ si wi fun awọn iranṣẹ rẹ pe,
Ayaṣebi arakọnrin nyin abikẹhin ba bá
nyin sọkalẹ wá, ẹnyin ki yio ri oju mi mọ́.
24 O si ṣe nigbati awa goke tọ̀ baba mi
iranṣẹ rẹ lọ, awa sọ̀rọ oluwa mi fun u.
25 Baba wa si wipe, Ẹ tun lọ irà onjẹ
diẹ fun wa wá.
26 Awa si wipe, Awa kò le sọkalẹ lọ:
bi arakọnrin wa abikẹhin ba pẹlu wa, njẹ
awa o sọkalẹ lọ; nitori ti awa ki o le ri
oju ọkọnrin na, bikoṣepe arakọnrin wa
abikẹhin ba pẹlu wa.
27 Baba mi iranṣẹ rẹ si wi fun wa pe,
Ẹnyin mọ̀ pe aya mi bí ọmọ meji fun mi:
28 Ọkan si ti ọdọ mi jade lọ, mo si
wipe, Nitõtọ a fà a ya pẹrẹpẹrẹ; emi kò si
ri i lati igbana wá:
29 Bi ẹnyin ba si mú eyi lọ lọwọ mi
pẹlu, ti ibi kan si ṣe e, ibinujẹ li ẹnyin o fi
mú ewú mi lọ si isà-okú.
30 Njẹ nisisiyi, nigbati mo ba dé ọdọ baba
mi, iranṣẹ rẹ, ti ọmọde na kò si wà pẹlu
wa; bẽni ẹmi rẹ̀ dìmọ́ ẹmi ọmọde na;
31 Yio si ṣe, bi o ba ri pe ọmọde na kò
pẹlu wa, yio kú: awọn iranṣẹ rẹ yio si fi

Digitized by Google

ibinujẹ mú ewú baba wa iranṣẹ rẹ lọ si isà-okú.

32 Nitori iranṣẹ rẹ li o ṣe onigbọwọ ọmọde na fun baba mi wipe, Bi emi kò ba mú u tọ̀ ọ wá, emi ni o gbà ẹbi na lọdọ baba mi lailai.

33 Njẹ nisisiyi emi bẹ̀ ọ, jẹ ki iranṣẹ rẹ ki o joko ni ipò ọmọde na li ẹrú fun oluwa mi; ki o si jẹ ki ọmọde na ki o bá awọn arakọnrin rẹ̀ goke lọ.

34 Nitori bi bawo li emi o fi goke tọ̀ baba mi lọ ki ọmọde na ki o ma wà pẹlu mi? ki emi má ba ri ibi ti mbọ̀wá bá baba mi.

## ORI 45.

NIGBANA ni Josefu kò le mu oju dá mọ́ niwaju gbogbo awọn ti o duro tì i; o si kigbe pe, Ẹ mu ki gbogbo enia ki o jade kuro lọdọ mi. Ẹnikẹni kò si duro tì i, nigbati Josefu sọ ara rẹ̀ di mimọ̀ fun awọn arakọnrin rẹ̀.

2 O si sọkun kikan: ati awọn ara Egipti ati awọn ara ile Farao gbọ́.

3 Josefu si wi fun awọn arakọnrin rẹ̀ pe, Emi ni Josefu; baba mi wà sibẹ̀? awọn arakọnrin rẹ̀ kò si le da a lohùn; nitori ti ẹ̀ru bà wọn niwaju rẹ̀.

4 Josefu si wi fun awọn arakọnrin rẹ̀ pe, Emi bẹ̀ nyin ẹ sunmọ ọdọ mi. Nwọn si sunmọ ọ. O si wi pe, Emi ni Josefu, arakọnrin nyin, ti ẹnyin tà si Egipti.

5 Njẹ nisisiyi, ẹ máṣe binujẹ, ki ẹ má si ṣe binu si ara nyin, ti ẹnyin tà mi si ihin: nitori pe, Ọlọrun li o rán mi siwaju nyin lati gbà ẹmi là.

6 Lati ọdún meji yi ni ìyan ti nmú ni ilẹ: o si tun kù ọdún marun si i, ninu eyiti a ki yio ni itulẹ tabi ikorè.

7 Ọlọrun si rán mi siwaju nyin lati dá iru-ọmọ si fun nyin lori ilẹ, ati lati fi ìgbala nla gbà ẹmi nyin là.

8 Njẹ nisisiyi, ki iṣe ẹnyin li o rán mi si ihin, bikoṣe Ọlọrun: o si ti fi mi ṣe baba fun Farao, ati oluwa gbogbo ile rẹ̀, ati alakoso gbogbo ilẹ Egipti.

9 Ẹ yara ki ẹ si goke tọ̀ baba mi lọ, ki ẹ si wi fun u pe, Bayi ni Josefu ọmọ rẹ wipe, Ọlọrun fi mi jẹ oluwa gbogbo Egipti: sọkalẹ tọ̀ mi wá, má si ṣe duro.

10 Iwọ o si joko ni ilẹ Goṣeni, iwọ o si wà leti ọdọ mi, iwọ, ati awọn ọmọ rẹ, ati awọn ọmọ ọmọ rẹ, ati ọwọ-ẹran rẹ, ati ọwọ́-malu rẹ, ati ohun gbogbo ti iwọ ní.

11 Nibẹ̀ li emi o si ma bọ́ ọ; nitori ọdún ìyan kù marun si i; ki iwọ, ati awọn ara ile rẹ, ati ohun gbogbo ti iwọ ní, ki o má ba ri ipọnju.

12 Si kiyesi i, oju nyin, ati oju Benjamini arakọnrin mi ri pe, ẹnu mi li o nsọ̀rọ fun nyin.

13 Ki ẹnyin ki o si ròhin gbogbo ogo mi ni Egipti fun baba mi, ati ti ohun gbogbo ti ẹnyin ri; ki ẹnyin ki o si yara, ki ẹ si mú baba mi sọkalẹ wá ihin.

14 O si rọ̀mọ́ Benjamini arakọnrin rẹ̀ li ọrùn, o si sọkun; Benjamini si sọkun li ọrùn rẹ̀.

15 O si fi ẹnu kò gbogbo awọn arakọnrin rẹ̀ li ẹnu, o si sọkun si wọn lara: lẹhin eyini li awọn arakọnrin rẹ̀ bá a sọ̀rọ.

16 A si gbọ́ ìhin na ni ile Farao pe, awọn arakọnrin Josefu dé: o si dùn mọ́ Farao ati awọn iranṣẹ rẹ̀.

17 Farao si wi fun Josefu pe, Wi fun awọn arakọnrin rẹ, Eyi ni ki ẹ ṣe; ẹ dì ẹrù lé ẹranko nyin, ki ẹ si lọ si ilẹ Kenaani;

18 Ẹ si mú baba nyin, ati awọn ara ile nyin, ki ẹ si tọ̀ mi wá; emi o si fun nyin li ohun rere ilẹ Egipti, ẹnyin o si ma jẹ ọrá ilẹ yi.

19 Njẹ a fun ọ li aṣẹ, eyi ni ki ẹ ṣe; ẹ mú kẹkẹ́-ẹrù lati ilẹ Egipti fun awọn ọmọ wẹrẹ nyin, ati fun awọn aya nyin, ki ẹ si mú baba nyin, ki ẹ si wá.

20 Ẹ má si ṣe aniyàn ohun-èlo; nitori ohun rere gbogbo ilẹ Egipti ti nyin ni.

21 Awọn ọmọ Israeli si ṣe bẽ: Josefu si fi kẹkẹ́-ẹrù fun wọn, gẹgẹ bi aṣẹ Farao, o si fi onjẹ ọ̀na fun wọn.

22 O fi ìparọ́-aṣọ fun gbogbo wọn fun olukuluku wọn; ṣugbọn Benjamini li o fi ọdunrun owo fadaka fun, ati ìparọ-aṣọ marun.

23 Bayi li o si ranṣẹ si baba rẹ̀; kẹtẹkẹtẹ mẹwa ti o rù ohun rere Egipti, ati abo-kẹtẹkẹtẹ mẹwa ti o rù ọkà ati àkara ati onjẹ fun baba rẹ̀ li ọ̀na.

24 Bẽli o rán awọn arakọnrin rẹ̀ lọ, nwọn si lọ: o si wi fun wọn pe, Ẹ máṣe jà li ọ̀na.

25 Nwọn si goke lati ilẹ Egipti lọ, nwọn si dé ọdọ Jakobu baba wọn ni ilẹ Kenaani.

26 Nwọn si wi fun u pe, Josefu mbẹ lãye sibẹ̀, on si ni bãlẹ gbogbo ilẹ Egipti. O si rẹ̀ Jakobu dé inu nitori ti kò gbà wọn gbọ́.

27 Nwọn si sọ ọ̀rọ Josefu gbogbo fun u, ti o wi fun wọn: nigbati o si ri kẹkẹ́-ẹrù ti Josefu rán wá lati fi mú u lọ, ọkàn Jakobu baba wọn sọji:

Digitized by Google

28 Israeli si wipe, O tó; Josefu ọmọ mi
mbẹ lãye sibẹ̀; emi o lọ ki nsi ri i ki emi
ki o to kú.

## ORI 46.

ISRAELI si mú ọ̀na àjo rẹ̀ pọ̀n ti on ti
ohun gbogbo ti o ní, o si dé Beer-ṣeba,
o si rú ẹbọ si Ọlọrun Isaaki baba rẹ̀.
2 Ọlọrun si bá Israeli sọ̀rọ li ojuran li
oru, o si wipe, Jakobu, Jakobu. O si
wipe, Emi niyi.
3 O si wipe, Emi li Ọlọrun, Ọlọrun baba
rẹ: má bẹ̀ru lati sọkalẹ lọ si ilẹ Egipti;
nitori ibẹ̀ li emi o gbé sọ iwọ di orilẹ-ède
nla.
4 Emi o si bá ọ sọkalẹ lọ si Egipti; emi
o si mú ọ goke wá nitõtọ: Josefu ni yio si
fi ọwọ́ rẹ̀ pa ọ li oju dé.
5 Jakobu si dide lati Beer-ṣeba lọ:
awọn ọmọ Israeli si mú Jakobu baba wọn
lọ, ati awọn ọmọ wẹrẹ wọn, ati awọn aya
wọn, ninu kẹkẹ́-ẹrù ti Farao rán lati mú
u lọ.
6 Nwọn si mú ẹran wọn, ati ẹrù wọn, ti
nwọn ní ni ilẹ Kenaani, nwọn si wá si Egipti,
Jakobu, ati gbogbo irú-ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀:
7 Awọn ọmọ rẹ̀, ati awọn ọmọ ọmọ rẹ̀
pẹlu rẹ̀, ati awọn ọmọbirin rẹ̀, ati awọn
ọmọbirin awọn ọmọ rẹ̀, gbogbo irú-ọmọ rẹ̀
li o mú pẹlu rẹ̀ wá si ilẹ Egipti.
8 Wọnyi si li orukọ awọn ọmọ Israeli,
ti o wá si Egipti, Jakobu ati awọn ọmọ rẹ̀:
Reubeni, akọ́bi Jakobu.
9 Ati awọn ọmọ Reubeni; Hanoku, ati
Pallu, ati Hesroni, ati Karmi.
10 Ati awọn ọmọ Simeoni; Jemueli, ati
Jamini, ati Ohadi, ati Jakini, ati Sohari,
ati Ṣaulu, ọmọ obirin ara Kenaani kan.
11 Ati awọn ọmọ Lefi; Gerṣoni, Kohati,
ati Merari.
12 Ati awọn ọmọ Judah; Eri ati Onani,
ati Ṣela, ati Peresi, ati Sera: ṣugbọn Eri
on Onani ti kú ni ilẹ Kenaani. Ati awọn
ọmọ Peresi ni Hesroni on Hamulu.
13 Ati awọn ọmọ Issakari; Tola, ati
Pufa, ati Jobu, ati Simroni.
14 Ati awọn ọmọ Sebuluni; Seredi, ati
Eloni, ati Jaleeli.
15 Awọn wọnyi li awọn ọmọ Lea, ti o
bí fun Jakobu ni Padan-aramu, pẹlu Dina
ọmọbirin rẹ̀: gbogbo ọkàn awọn ọmọ rẹ̀
ọkọnrin ati awọn ọmọ rẹ̀ obirin, o jẹ́ mẹta-
lelọgbọ̀n.
16 Ati awọn ọmọ Gadi; Sifioni, ati
Haggi, Ṣuni, ati Esboni, Eri, ati Arodi, ati
Areli.
17 Ati awọn ọmọ Aṣeri; Jimna, ati Iṣua,
ati Isui, ati Beria, ati Sera arabirin wọn:
ati awọn ọmọ Beria; Heberi, ati Malkieli.
18 Wọnyi li awọn ọmọ Silpa, ti Labani
fi fun Lea ọmọbirin rẹ̀, wọnyi li o si bí fun
Jakobu, ọkàn mẹrindilogun.
19 Awọn ọmọ Rakeli aya Jakobu; Jo-
sefu ati Benjamini.
20 Manasse ati Efraimu li a si bí fun
Josefu ni ilẹ Egipti, ti Asenati ọmọbirin
Potifera alufa Oni bí fun u.
21 Ati awọn ọmọ Benjamini; Bela, ati
Bekeri, ati Aṣbeli, Gera, ati Naamani, Ehi,
ati Roṣi, Muppimu, ati Huppimu, ati
Ardi.
22 Wọnyi li awọn ọmọ Rakeli, ti a bí
fun Jakobu: gbogbo ọkàn na jẹ́ mẹrinla.
23 Ati awọn ọmọ Dani; Huṣimu.
24 Ati awọn ọmọ Naftali; Jahseeli, ati
Guni, ati Jeseri, ati Ṣillemu.
25 Wọnyi si li awọn ọmọ Bilha, ti La-
bani fi fun Rakeli ọmọbirin rẹ̀, o si bí wọn-
yi fun Jakobu: gbogbo ọkàn na jẹ́ meje.
26 Gbogbo ọkàn ti o ba Jakobu wá si
Egipti, ti o si ti inu Jakobu jade, li àika
aya awọn ọmọ Jakobu, ọkàn na gbogbo jẹ́
mẹrindilãdọrin;
27 Ati awọn ọmọ Josefu ti a bí fun u ni
Egipti jẹ́ ọkàn meji; gbogbo ọkàn ile Ja-
kobu, ti o wá si ilẹ Egipti jẹ́ ãdọrin ọkàn.
28 O si rán Judah ṣiwaju rẹ̀ si Josefu ki
o kọju wọn si Goṣeni; nwọn si dé ilẹ
Goṣeni.
29 Josefu si dì kẹkẹ́ rẹ̀, o si lọ si Goṣeni
lọ ipade Israeli baba rẹ̀, o si fi ara rẹ̀ hàn
a; on si rọ̀ mọ́ ọ li ọrùn, o si sọkun si i li
ọrùn pẹ titi.
30 Israeli si wi fun Josefu pe, Jẹ ki emi
ki o kú wayi, bi mo ti ri oju rẹ yi, nitori
ti iwọ wà lãye sibẹ̀.
31 Josefu si wi fun awọn arakọnrin rẹ̀,
ati fun awọn ara ile baba rẹ̀ pe, Emi o goke
lọ, emi o si sọ fun Farao, emi o si wi fun
u pe, Awọn arakọnrin mi, ati awọn ara ile
baba mi, ti o wà ni ilẹ Kenaani, nwọn tọ̀
mi wá;
32 Oluṣọ-agutan si li awọn ọkọnrin na,
ẹran sisin ni iṣẹ wọn; nwọn si dà agbo-
ẹran ati ọwọ́-ẹran wọn wá, ati ohun gbogbo
ti nwọn ní.
33 Yio si ṣe, nigbati Farao ba pè nyin,
ti yio si bi nyin pe, Kini iṣẹ nyin?
34 Ki ẹnyin ki o wipe, Owo awọn iran-
ṣẹ rẹ li ẹran sisin lati igba ewe wa wá titi
o fi di isisiyi, ati awa, ati awọn baba wa
pẹlu: ki ẹnyin ki o le joko ni ilẹ Goṣeni;

Digitized by Google

nitori irira li olusọ-agutan gbogbo si awọn
ara Egipti.

## ORI 47.

NIGBANA ni Josefu wọle, o si sọ fun
Farao, o si wipe, Baba mi, ati awọn
arakọnrin mi ati ọwọ́-ẹran wọn, ati ọwọ́-
malu wọn, ati ohun gbogbo ti nwọn ní,
nwọn ti ilẹ Kenaani wá ; si kiyesi i, nwọn
mbẹ ni ilẹ Goṣeni.
2 O si mú marun ninu awọn arakọnrin
rẹ̀, o si mu wọn duro niwaju Farao.
3 Farao si bi awọn arakọnrin rẹ̀ pe, Ki-
ni iṣẹ nyin ? Nwọn si wi fun Farao pe,
Olusọ-agutan li awọn iranṣẹ rẹ, ati awa, ati
awọn baba wa pẹlu.
4 Nwọn si wi fun Farao pẹlu pe, Nitori
ati ṣe atipo ni ilẹ yi li awa ṣe wá ; nitori
awọn iranṣẹ rẹ kò ní papa oko tutù fun
ọwọ́-ẹran wọn ; nitori ti ìyan yi mú gidi-
gidi ni ilẹ Kenaani : njẹ nitorina awa bẹ̀ o,
jẹ ki awọn iranṣẹ rẹ ki o joko ni ilẹ Goṣe-
ni.
5 Farao si wi fun Josefu pe, Baba rẹ ati
awọn arakọnrin rẹ̀ tọ̀ ọ wá :
6 Ilẹ Egipti niyi niwaju rẹ ; ninu ãyo
ilẹ ni ki o mu baba ati awọn arakọnrin rẹ
joko ; jẹ ki nwọn ki o joko ni ilẹ Goṣeni :
bi iwọ ba si mọ̀ ẹnikẹni ti o li ãpọn ninu
wọn, njẹ ki iwọ ki o ṣe wọn li olori lori
ẹran-ọsin mi.
7 Josefu si mú Jakobu baba rẹ̀ wọle wá,
o si mu u duro niwaju Farao : Jakobu si
sure fun Farao.
8 Farao si bi Jakobu pe, Ọdún melo li
ọjọ́ aiye rẹ ?
9 Jakobu si wi fun Farao pe, Ãdoje
ọdún li ọjọ́ atipo mi : diẹ ti on ti buburu
li ọdún ọjọ́ aiye mi jẹ́, nwọn kò si ti idé
ọdún ọjọ́ aiye awọn baba mi li ọjọ́ atipo
wọn.
10 Jakobu si sure fun Farao, o si jade
kuro niwaju Farao.
11 Josefu si fi baba rẹ̀ ati awọn arakọn-
rin rẹ̀ joko, o si fun wọn ni iní ni ilẹ
Egipti, ni ibi ãyo ilẹ, ni ilẹ Ramesesi, bi
Farao ti pa li aṣẹ.
12 Josefu si fi onjẹ bọ́ baba rẹ̀, ati awọn
arakọnrin rẹ̀, ati gbogbo ile baba rẹ̀, gẹgẹ
bi iye awọn ọmọ wọn.
13 Onjẹ kò si sí ni gbogbo ilẹ ; nitori ti
ìyan na mú gidigidi, tobẹ̃ ti ilẹ Egipti ati
gbogbo ilẹ Kenaani gbẹ nitori ìyan na.
14 Josefu si kó gbogbo owo ti a ri ni ilẹ
Egipti ati ni ilẹ Kenaani jọ, fun ọkà ti nwọn
rà : Josefu si kó owo na wá si ile Farao.
15 Nigbati owo si tán ni ilẹ Egipti, ati
ni ilẹ Kenaani, gbogbo awọn ara Egipti tọ̀
Josefu wá, nwọn si wipe, Fun wa li onjẹ :
nitori kili awa o ṣe kú li oju rẹ ? owo sa tán.
16 Josefu si wipe, Ẹ mú ẹran nyin wá,
emi o si fun nyin dipò ẹran nyin, bi owo ba
tán.
17 Nwọn si mú ẹran wọn tọ̀ Josefu wá :
Josefu si fun wọn li onjẹ dipò ẹṣin, ati ọwọ́-
ẹran, ati dipò ọwọ́-malu, ati kẹtẹkẹtẹ : o si
fi onjẹ bọ́ wọn dipò gbogbo ẹran wọn li ọdún
na.
18 Nigbati ọdún na si pari, nwọn si tọ̀ ọ
wá li ọdún keji, nwọn si wi fun u pe, Awa
ki yio pa a mọ́ lọdọ oluwa mi, bi a ti ná
owo wa tán ; ẹran-ọ̀sin si ti di ti oluwa mi ;
kò si sí nkan ti o kù li oju oluwa mi, bi-
koṣe ara wa, ati ilẹ wa :
19 Nitori kili awa o ṣe kú li oju rẹ, ati
awa ati ilẹ wa ? fi onjẹ rà wa ati ilẹ wa, ati
awa ati ilẹ wa yio ma ṣe ẹrú Farao : ki o si
fun wa ni irugbìn, ki awa ki o le yè, ki a
má kú, ki ilẹ ki o má ṣe di ahoro.
20 Bẹ̃ni Josefu rà gbogbo ilẹ Egipti fun
Farao ; nitori olukuluku awọn ara Egipti
li o tà oko rẹ̀, nitori ti ìyan na mú wọn :
ilẹ si di ti Farao.
21 Bi o si ṣe ti awọn enia ni, o ṣí wọn si
ilu, lati opin ilẹ kan ni Egipti dé opin ilẹ
keji.
22 Kìki ilẹ awọn alufa ni kò rà ; nitori
ti awọn alufa ní ipín ti wọn lati ọwọ́ Farao
wá, nwọn si njẹ ipín wọn ti Farao fi fun
wọn ; nitorina ni nwọn kò fi tà ilẹ wọn.
23 Nigbana ni Josefu wi fun awọn enia
pe, Kiyesi i, emi ti rà nyin loni ati ilẹ nyin
fun Farao : wò o, irugbìn niyi fun nyin, ki
ẹnyin ki o si gbìn ilẹ na.
24 Yio si se, ni ikore ki ẹnyin ki o fi
ida-marun fun Farao, ọ̀na mẹrin yio jẹ́ ti
ara nyin fun irugbìn oko, ati fun onjẹ nyin,
ati fun awọn ara ile nyin, ati onjẹ fun awọn
ọmọ nyin wẹrẹ.
25 Nwọn si wipe, Iwọ ti gbà ẹmi wa là :
ki awa ki o ri ore-ọfẹ li oju oluwa mi, awa
o si ma ṣe ẹrú Farao.
26 Josfu si ṣe e ni ilana ni ilẹ Egipti
titi di oni-oloni pe, Farao ni yio ma ní ida-
marun ; bikoṣe ilẹ awọn alufa nikan ni kò
di ti Farao.
27 Israeli si joko ni ilẹ Egipti, ni ilẹ
Goṣeni ; nwọn si ní iní nibẹ̀, nwọn bísi i,
nwọn si rẹ̀ gidigidi.
28 Jakobu si wà li ọdún mẹtadilogun ni
ilẹ Egipti ; gbogbo ọjọ́ aiye Jakobu si jẹ́
ãdọjọ ọdún o dí mẹta :

Digitized by Google

29 Akokò Israeli si sunmọ-etile ti yio
kú: o si pè Josefu ọmọ rẹ̀, o si wi fun u pe,
Emi bẹ̀ ọ, bi emi ba ri ojurere li oju rẹ, jọ̃,
fi ọwọ́ rẹ si abẹ itan mi, ki o si ṣe ãnu ati
otitọ fun mi; emi bẹ̀ ọ, máṣe sin mi ni
Egipti.
30 Ṣugbọn nigbati emi ba sùn pẹlu awọn
baba mi, iwọ o gbe mi jade ni Egipti, ki o
si sin mi ni iboji wọn. On si wipe, Emi o
ṣe bi iwọ ti wi.
31 O si wipe, Bura fun mi. On si bura
fun u. Israeli si tẹriba lori akete.

## ORI 48.

O SI ṣe lẹhin nkan wọnyi ni ẹnikan wi fun
Josefu pe, Kiyesi i, ara baba rẹ kò dá:
o si mú awọn ọmọ rẹ̀ mejeji, Manasse ati
Efraimu pẹlu rẹ̀.
2 Ẹnikan si sọ fun Jakobu, o si wipe,
Kiyesi i, Josefu ọmọ rẹ tọ̀ ọ wá: Israeli si
gbiyanju, o si joko lori akete.
3 Jakobu si wi fun Josefu pe, Ọlọrun
Olodumare farahàn mi ni Lusi ni ilẹ Kena-
ani, o si sure fun mi,
4 O si wi fun mi pe, Kiyesĩ, Emi o mu
ọ bisi i, Emi o mu ọ rẹ̀, Emi o si sọ ọ di
ọ̀pọlọpọ enia; Emi o si fi ilẹ yi fun irú-
ọmọ rẹ lẹhin rẹ ni iní titi aiye.
5 Njẹ nisisiyi Efraimu ati Manasse,
awọn ọmọ rẹ mejeji ti a bí fun ọ ni ilẹ
Egipti, ki emi ki o tó tọ̀ ọ wá ni Egipti, ti
emi ni nwọn: bi Reubeni on Simeoni,
bẹ̃ni nwọn o jẹ́ ti emi.
6 Ṣugbọn awọn ọmọ rẹ ti iwọ bí lẹhin
wọn ni yio ṣe tirẹ, a o si ma pè wọn li oru-
kọ awọn arakọnrin wọn ni ilẹ iní wọn.
7 Ati emi, nigbati mo ti Paddani wá,
Rakeli kú lọwọ mi ni ilẹ Kenaani li ọ̀na,
nigbati o kù diẹ ti a ba fi dé Efrati: emi si
sin i nibẹ̀ li ọ̀na Efrati (eyi na ni Betlehe-
mu).
8 Israeli si wò awọn ọmọ Josefu, o si
bère pe, Tani wọnyi?
9 Josefu wi fun baba rẹ̀ pe, Awọn ọmọ
mi ni, ti Ọlọrun fifun mi nihinyi. O si
wipe, Emi bẹ̀ ọ, mú wọn wá sọdọ mi, emi
o si sure fun wọn.
10 Njẹ oju Israeli ṣú bàibai nitori ogbó,
kò le riran. On si mú wọn sunmọ ọdọ rẹ̀:
o si fi ẹnu kò wọn li ẹnu, o si gbá wọn
mọra.
11 Israeli si wi fun Josefu pe, Emi kò
dába ati ri oju rẹ mọ́: si kiyesi i, Ọlọrun
si fi irú-ọmọ rẹ hàn mi pẹlu.
12 Josefu si mú wọn kuro li ẽkun rẹ̀, o
si tẹriba, o dà oju rẹ̀ bolẹ.
13 Josefu si mú awọn mejeji, Efraimu li
ọwọ́ ọtún rẹ̀ si ọwọ́ òsi Israeli, ati Manasse
lọwọ òsi rẹ̀, si ọwọ́ ọtún Israeli, o si mú
wọn sunmọ ọdọ rẹ̀.
14 Israeli si nà ọwọ́ ọtún rẹ̀, o si fi lé
Efraimu ẹniti iṣe aburo li ori, ati ọwọ́ òsi
rẹ̀ lé ori Manasse, o mọ̃mọ̀ mu ọwọ́ rẹ̀ lọ
bẹ̃: nitori Manasse ni iṣe akọ́bi.
15 O si sure fun Josefu, o si wipe, Ọlọ-
run, niwaju ẹniti Abrahamu ati Isaaki
awọn baba mi rìn, Ọlọrun na ti o bọ́ mi
lati ọjọ́ aiye mi titi di oni,
16 Angeli na ti o dá mi ni ìde kuro ninu
ibi gbogbo, ki o gbè awọn ọmọde wọnyi;
ki a si pè orukọ mi mọ́ wọn lara, ati orukọ
Abrahamu ati Isaaki awọn baba mi; ki
nwọn ki o si di ọ̀pọlọpọ lãrin aiye.
17 Nigbati Josefu ri pe baba rẹ̀ fi ọwọ́
ọtún rẹ̀ lé Efraimu lori, inu rẹ̀ kò dùn: o
si mú baba rẹ̀ li ọwọ́, lati ṣí i kuro li ori
Efraimu si ori Manasse.
18 Josefu si wi fun baba rẹ̀ pe, Bẹ̃kọ,
baba mi: nitori eyi li akọ́bi; fi ọwọ́ ọtún
rẹ lé e li ori.
19 Baba rẹ̀ si kọ̀, o si wipe, Emi mọ̀,
ọmọ mi, emi mọ̀: on pẹlu yio di enia, yio
si pọ̀ pẹlu: ṣugbọn nitõtọ aburo rẹ̀ yio jù u
lọ, irú-ọmọ rẹ̀ yio si di ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède.
20 O si sure fun wọn li ọjọ́ na pe, Iwọ ni
Israeli o ma fi sure, wipe, Ki Ọlọrun ki o ṣe
nyin bi Efraimu on Manasse: bẹ̃li o fi
Efraimu ṣaju Manasse.
21 Israeli si wi fun Josefu pe, Wò o, emi
kú: ṣugbọn Ọlọrun yio wà pẹlu nyin, yio
si tun mú nyin lọ si ilẹ awọn baba nyin.
22 Pẹlupẹlu, emi si fi ilẹ-biri kan fun ọ
jù awọn arakọnrin rẹ lọ, ti mo fi idà ti on
ti ọrun mi gbà lọwọ awọn enia Amori.

## ORI 49.

JAKOBU si pè awọn ọmọ rẹ̀, o si wipe, Ẹ
kó ara nyin jọ, ki emi ki o le wi ohun
ti yio bá nyin lẹhin-ọla fun nyin.
2 Ẹ kó ara nyin jọ, ki ẹ si gbọ́, ẹnyin ọmọ
Jakobu; ki ẹ si fetisi ti Israeli baba nyin.
3 Reubeni, iwọ li akọ́bi mi, agbara mi,
ati ipilẹṣe ipá mi, titayọ ọlá, ati titayọ
agbara.
4 Ẹnirirú bi omi, iwọ ki yio le tayọ;
nitori ti iwọ gùn ori ẹni baba rẹ; iwọ si
bà a jẹ́: o gùn ori akete mi.
5 Simeoni on Lefi, arakọnrin ni nwọn;
ohun-èlo ìka ni idà wọn.
6 Ọkàn mi, iwọ máṣe wọ̀ ìmọ wọn;
ninu ajọ wọn, ọlá mi, máṣe bá wọn dàpọ;
nitoripe, ni ibinu wọn nwọn pa ọkọnrin

Digitized by Google

kan, ati ni girimakayi wọn, nwọn já malu ni patì.

7 Ifibú ni ibinu wọn, nitori ti o rorò; ati ikannu wọn, nitori ti o ní ìka: emi o pin wọn ni Jakobu, emi o si tú wọn ká ni Israeli.

8 Judah, iwọ li ẹniti awọn arakọnrin rẹ yio ma yìn; ọwọ́ rẹ yio wà li ọrùn awọn ọtá rẹ; awọn ọmọ baba rẹ yio foribalẹ niwaju rẹ.

9 Ọmọ kiniun ni Judah; ọmọ mi, ni ibi-ọdẹ ni iwọ ti goke: o bẹ̀rẹ, o ba bi kiniun, ati bi ogbó kiniun; tani yio lé e dide?

10 Ọpá-alade ki yio ti ọwọ́ Judah kuro, bẽli olofin ki yio kuro lãrin ẹsẹ̀ rẹ̀, titi Ṣiloh yio fi dé; on li awọn enia yio gbọ́ tirẹ̀.

11 Yio ma so ọmọ ẹsin rẹ̀ mọ́ ara àjara, ati ọmọ kẹtẹkẹtẹ rẹ̀ mọ́ ara ãyo àjara; o ti fọ̀ ẹ̀wu rẹ̀ ninu ọtí-waini, ati aṣọ rẹ̀ ninu ẹ̀jẹ eso àjara:

12 Oju rẹ̀ yio pọ́n fun ọtí-waini, ehín rẹ̀ yio si funfun fun wàra.

13 Sebuloni ni yio ma gbé ebute okun: on ni yio si ma wà fun ebute ọkọ̀; ipinlẹ rẹ̀ yio si dé Sidoni.

14 Issakari ni kẹtẹkẹtẹ ti o lera, ti o dubulẹ lãrin awọn agbo-agutan.

15 O si ri pe isimi dara, ati ilẹ na pe o wuni; o si tẹ̀ ejiká rẹ̀ lati rẹrù, on si di ẹni nsìnrú.

16 Dani yio ma ṣe idajọ awọn enia rẹ̀, bi ọkan ninu awọn ẹ̀ya Israeli.

17 Dani yio dabi ejò li ẹba ọ̀na, bi paramọlẹ li ọ̀na, ti ibù ẹṣin ṣán ni gigĩsẹ, tòbẽ ti ẹniti o gùn u yio fi ṣubu sẹhin.

18 Emi ti duro dè ìgbala rẹ, OLUWA!

19 Gadi ọwọ́-ogun ni yio kọlù u: ṣugbọn on lé wọn.

20 Lati inu Aṣeri wá onjẹ rẹ̀ yio lọrá, on o si ma mú adidùn ọba wá.

21 Naftali li abo-agbọnrin ti o le sare: o funni li ọ̀rọ rere.

22 Josefu li ẹka eleso pupọ̀, ẹka eleso pupọ̀ li ẹba kanga; ẹtun ẹniti o yọ si ori ogiri.

23 Awọn tafàtafa bà a ninu jẹ́ pọ̀ju, nwọn si tafà si i, nwọn si korira rẹ̀:

24 Ṣugbọn ọrun rẹ̀ joko li agbara, a si mú apa ọwọ́ rẹ̀ larale, lati ọwọ́ Alagbara Jakobu wá, (lati ibẹ̀ li oluṣọ-agutan, okuta Israeli,)

25 Ani lati ọwọ́ Ọlọrun baba rẹ wá, ẹniti yio ràn ọ lọwọ; ati lati ọwọ́ Olodumare wá, ẹniti yio fi ibukún lati oke ọrun busi i fun ọ, ibukún ọgbun ti o wà ni isalẹ, ibukún ọmú, ati ti inu.

26 Ibukún baba rẹ ti jù ibukún awọn baba nla mi lọ, titi dé opin oke aiyeraiye wọnni: nwọn o si ma gbé ori Josefu, ati li atari ẹniti a yàsọtọ lãrin awọn arakọnrin rẹ̀.

27 Benjamini ni yio ma fàniya bi ikõkò: ni kutukutu ni yio ma jẹ ẹran-ọdẹ rẹ̀, ati li aṣalẹ ni yio ma pín ikogun rẹ̀.

28 Gbogbo wọnyi li awọn ẹ̀ya Israeli mejejila: eyi ni baba wọn si sọ fun wọn, o si sure fun wọn; olukuluku bi ibukún tirẹ̀, li o sure fun wọn.

29 O si kilọ fun wọn, o si sọ fun wọn pe, A o kó mi jọ pọ̀ pẹlu awọn enia mi: ẹ sin mi pẹlu awọn baba mi ni ihò ti o mbẹ li oko Efroni ara Hitti.

30 Ninu ihò ti o mbẹ ninu oko Makpela ti mbẹ niwaju Mamre, ni ilẹ Kenaani, ti Abrahamu rà pẹlu oko lọwọ Efroni, ara Hitti fun ilẹ-isinku.

31 Nibẹ̀ ni nwọn sin Abrahamu ati Sara aya rẹ̀; nibẹ̀ ni nwọn sin Isaaki ati Rebeka aya rẹ̀; nibẹ̀ ni mo si sin Lea:

32 Lọwọ awọn ọmọ Heti li a ti rà oko na ti on ti ihò ti o wà nibẹ̀.

33 Nigbati Jakobu si ti pari aṣẹ ipa fun awọn ọmọ rẹ̀, o kó ẹsẹ̀ rẹ̀ jọ sori akete, o si jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ, a si kó o jọ pẹlu awọn enia rẹ̀.

## ORI 50.

JOSEFU si ṣubu lé baba rẹ̀ li oju, o si sọkun si i lara, o si fi ẹnu kò o li ẹnu.

2 Josefu si paṣẹ fun awọn iranṣẹ rẹ̀, awọn oniṣegun, ki nwọn ki o kùn baba on li ọṣẹ: awọn oniṣegun si kùn Israeli li ọṣẹ.

3 Nwọn si kún ogoji ọjọ́ fun u; nitoripe bẽli a ikún ọjọ́ awọn ti a kùn li ọṣẹ: awọn ara Egipti si ṣọ̀fọ rẹ̀ li ãdọrin ọjọ́.

4 Nigbati ọjọ́ ọ̀fọ rẹ̀ kọja, Josefu sọ fun awọn ara ile Farao pe, Njẹ bi emi ba ri oreọfẹ li oju nyin, emi bẹ̀ nyin, ẹ wi li eti Farao pe,

5 Baba mi mu mi bura wipe, Kiyesi i, emi kú: ni isà mi ti mo ti wà fun ara mi ni ilẹ Kenaani, nibẹ̀ ni ki iwọ ki o sin mi. Njẹ nitorina emi bẹ̀ ọ, jẹ ki emi ki o goke lọ, ki emi ki o si lọ isin baba mi, emi o si tun pada wá.

6 Farao si wipe, Goke lọ, ki o si sin okú baba rẹ, gẹgẹ bi o ti mu ọ bura.

7 Josefu si goke lọ lati sin baba rẹ̀: ati gbogbo awọn iranṣẹ Farao, ati awọn àlagba ile rẹ̀, ati gbogbo awọn àlagba ilẹ Egipti si bá a goke lọ.

Digitized by Google

8 Ati gbogbo awọn ara ile Josefu, ati
awọn arakọnrin rẹ̀, ati awọn ara ile baba
rẹ̀: kiki awọn ọmọ wẹ́wẹ wọn, ati ọwọ́-ẹran
wọn, ati ọwọ́-malu wọn, ni nwọn fi silẹ ni
ilẹ Goṣeni.
9 Ati kẹkẹ́ ati ẹlẹṣin si bá a goke lọ:
ẹgbẹ nlanla si ni ẹgbẹ na.
10 Nwọn si dé ibi ilẹ ipakà Atadi, ti o
wà li oke Jordani, nibẹ̀ ni nwọn gbé si fi
ohùn rére ẹkún nlanla ṣọ̀fọ rẹ̀: o si ṣọ̀fọ fun
baba rẹ̀ li ọjọ́ meje.
11 Nigbati awọn ara ilẹ na, awọn ara
Kenaani, si ri ọ̀fọ na ni ibi ilẹ ipakà Atadi,
nwọn wipe, Ọ̀fọ nla li eyi fun awọn ara
Egipti: nitorina ni nwọn ṣe sọ orukọ rẹ̀ ni
Abel-misraimu, ti o wà loke odò Jordani.
12 Awọn ọmọ rẹ̀ si ṣe bi o ti fi aṣẹ fun
wọn:
13 Nitori ti awọn ọmọ rẹ̀ mú u lọ si ilẹ
Kenaani, nwọn si sin i ninu ihò oko Mak-
pela, ti Abrahamu rà pẹlu oko fun iní ilẹ
isinku, lọwọ Efroni ara Hitti, niwaju Mam-
re.
14 Josefu si pada wá si Egipti, on ati
awọn arakọnrin rẹ̀, ati gbogbo awọn ti o bá
a goke lọ lati sin baba rẹ̀, lẹhin ti o ti sin
baba rẹ̀ tán.
15 Nigbati awọn arakọnrin Josefu ri pe
baba wọn kú tán, nwọn wipe, Bọya Josefu
yio korira wa, yio si gbẹsan gbogbo ibi ti a
ti ṣe si i lara wa.
16 Nwọn si rán onṣẹ tọ̀ Josefu lọ wipe,
Baba rẹ ti paṣe ki o tó kú pe,
17 Bayi ni ki ẹnyin wi fun Josefu pe,
Njẹ emi bẹ̀ ọ, dari irekọja ati ẹ̀ṣẹ awọn
arakọnrin rẹ jì wọn, nitori ibi ti nwọn ṣe
si ọ. Njẹ nisisiyi, awa bẹ̀ ọ, dari irekọja
awọn iranṣẹ Ọlọrun baba rẹ jì wọn. Josefu
si sọkun nigbati nwọn sọ fun u.
18 Awọn arakọnrin rẹ̀ si lọ pẹlu, nwọn
wolẹ niwaju rẹ̀: nwọn si wipe, Wò o, iran-
ṣẹ rẹ li awa iṣe.
19 Josefu si wi fun wọn pe, Ẹ má bẹ̀ru:
emi ha wà ni ipò Ọlọrun?
20 Ṣugbọn bi o ṣe ti nyin ni, ibi li ẹnyin
rò si mi; ṣugbọn Ọlọrun mọ̀ ọ si rere, lati
mu u ṣẹ, bi o ti ri loni lati gbà ọ̀pọlọpọ enia
là.
21 Njẹ nisisiyi, ẹ má bẹ̀ru: emi o bọ́
nyin, ati awọn ọmọ wẹrẹ nyin. O si tù
wọn ninu, o si sọ̀rọ rere fun wọn.
22 Josefu si joko ni Egipti, on ati ile
baba rẹ̀: Josefu si wà li ãdọfa ọdún.
23 Josefu si ri awọn ọmọloju Efraimu ti
iran kẹta; awọn ọmọ Makiri, ọmọ Manasse
li a si gbé kà ori ẽkun Josefu pẹlu.
24 Josefu si wi fun awọn arakọnrin rẹ̀
pe, Emi kú: Ọlọrun yio si bẹ̀ nyin wò ni-
tõtọ, yio si mú nyin jade kuro ni ilẹ yi, si
ilẹ ti o ti bura fun Abrahamu, fun Isaaki,
ati fun Jakobu.
25 Josefu si mu awọn ọmọ Israeli bura,
wipe, Ọlọrun yio bẹ̀ nyin wò nitõtọ, ki
ẹnyin ki o si rù egungun mi lati ihin lọ.
26 Bẹ̃ni Josefu kú, o jẹ́ ẹni ãdọfa ọdún:
nwọn si kùn u li ọṣẹ, a si tẹ́ ẹ sinu posi ni
Egipti.

---

IWE KEJI MOSE,

TI A NPE NI

# EKSODU.

## ORI 1.

NJẸ orukọ awọn ọmọ Israeli, ti o wá si
Egipti pẹlu Jakobu ni wọnyi; oluku-
luku pẹlu ile rẹ̀.
2 Reubeni, Simeoni, Lefi, ati Judah;
3 Issakari, Sebuluni, ati Benjamini;
4 Dani ati Naftali, Gadi ati Aṣeri.
5 Ati gbogbo ọkàn ti o ti inu Jakobu
jade, o jẹ́ ãdọrin ọkàn: Josefu sa ti wà ni
Egipti.
6 Josefu si kú, ati gbogbo awọn arakọn-
rin rẹ̀, ati gbogbo iran na.
7 Awọn ọmọ Israeli si bisi i, nwọn si
pọ̀si i gidigidi, nwọn si rẹ̀, nwọn si di ala-
gbara nla jọjọ; ilẹ na si kún fun wọn.

Digitized by Google

8 Ọba titun miran si wa ijẹ ni Egipti,
ti kò mọ̀ Josefu.
9 O si wi fun awọn enia rẹ̀ pe, kiye si i,
enia awọn ọmọ Israeli npọ̀, nwọn si nla-
gbara jù wa lọ:
10 Ẹ wá na, ẹ jẹ ki a fi ọgbọ́n ba wọn ṣe;
ki nwọn ki o máṣe bisi i, yio si ṣe nigbati
ogun kan ba ṣẹ̀, nwọn o dápọ mọ́ awọn ọtá
wa pẹlu, nwọn o má bá wa jà, nwọn o si
jade kuro ni ilẹ yi.
11 Nitorina ni nwọn ṣe yàn akoniṣiṣẹ le
wọn, lati fi iṣẹ wọn pọ́n wọn loju. Nwọn
si kọ́ ilu iṣura fun Farao, Pitomu ati Ra-
amsesi.
12 Bi nwọn si ti npọ́n wọn loju si i, bẹ̃-
ni nwọn mbisi i, ti nwọn si npọ̀. Inu wọn
si bàjẹ́ nitori awọn ọmọ Israeli.
13 Awọn ara Egipti si mu awọn ọmọ
Israeli sìn li asìnpa:
14 Nwọn si fi ìsin lile, li erupẹ ati ni
briki ṣiṣe, ati ni oniruru ìsin li oko mu
aiye wọn korò: gbogbo ìsin wọn ti nwọn
mu wọn sìn, asìnpa ni.
15 Ọba Egipti si wi fun awọn iyãgbà
Heberu; orukọ ọkan ninu ẹniti ijẹ Ṣifra,
ati orukọ ekeji ni Pua:
16 O si wipe, Nigbati ẹnyin ba nṣe iṣẹ
iyãgbà fun awọn obirin Heberu, ti ẹnyin
ba ri wọn ni ikunlẹ; bi o ba ṣe ọmọkọnrin
ni, njẹ ki ẹnyin ki o pa a; ṣugbọn bi o ba
ṣe ọmọbirin ni, njẹ on o yè.
17 Ṣugbọn awọn iyãgbà bẹ̀ru Ọlọrun,
nwọn kò si ṣe bi ọba Egipti ti fi aṣẹ fun
wọn, nwọn si da awọn ọmọkọnrin si.
18 Ọba Egipti si pè awọn iyãgbà na,
o si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi ṣe
irù nkan yi ti ẹnyin si da awọn ọmọkọ-
nrin si?
19 Awọn iyãgbà si wi fun Farao pe, ni-
toriti awọn obirin Heberu kò ri bi awọn
obirin Egipti; nitoriti ara yá wọn, nwọn
a si ti bí ki awọn iyãgbà to wọle tọ̀ wọn lọ.
20 Nitorina Ọlọrun ṣe rere fun awọn
iyãgbà na: awọn enia na si mbisi i, nwọn
si di alagbara koko.
21 O si ṣe, nitoriti awọn iyãgbà bẹ̀ru
Ọlọrun, on si kọle fun wọn.
22 Farao si paṣẹ fun gbogbo awọn enia
rẹ̀, wipe, Gbogbo ọmọkọnrin ti a bí on ni
ki ẹnyin gbé ju sinu odò, gbogbo awọn ọ-
mọbirin ni ki ẹnyin ki o dasi.

## ORI 2.

OKỌNRIN kan ara ile Lefi si lọ, o si fẹ́
ọmọbirin Lefi kan.
2 Obirin na si yún, o si bi ọmọkọnrin
kan: nigbati o si ri i pe, o ṣe ọmọ didara,
o pa a mọ́ li oṣù mẹta.
3 Nigbati kò si le pa a mọ́ mọ́, o ṣe apo-
ti ẽsu fun u, o si fi ọ̀da ilẹ ati oje igi ṣán
a; o si tẹ́ ọmọ na sinu rẹ̀; o si gbé e sinu
koriko odò li ẹba odò na.
4 Arabirin rẹ̀ si duro li òkere, lati mọ̀
ohun ti yio ṣe ọmọ na.
5 Ọmọbirin Farao si sọkalẹ wá lati wẹ̀ li
odò; awọn ọmọbirin ọdọ rẹ̀ si nrìn lọ li ẹba
odò na; nigbati o si ri apoti na làrin kori-
ko odò, o rán ọmọbirin ọdọ rẹ̀ kan lati lọ
gbé e wá.
6 Nigbati o si ṣi i, o ri ọmọ na; si kiyesi
i ọmọde na nsọkun. Inu rẹ̀ si yọ́ si i, o
si wipe, Ọkan ninu awọn ọmọ Heberu li
eyi.
7 Nigbana li arabirin rẹ̀ wi fun ọmọbirin
Farao pe, Emi ka lọ ipè alagbatọ kan fun
ọ wá ninu awọn obirin Heberu, ki o tọ́ ọmọ
na fun ọ?
8 Ọmọbirin Farao si wi fun u pe, Lọ.
Ọmọbirin na si lọ, o si pè iya ọmọ na wá.
9 Ọmọbirin Farao si wi fun u pe, Gbé
ọmọ yi lọ ki o si tọ́ ọ fun mi, emi o si san
owo iṣẹ rẹ fun ọ. Obirin na si gbé ọmọ na
lọ, o si tọ́ ọ.
10 Ọmọ na si dàgba, o si mú u tọ̀ ọmọ-
birin Farao wá, on si di ọmọ rẹ̀. O si sọ
orukọ rẹ̀ ni Mose, o si wipe, Nitoriti mo fà
a jade ninu omi.
11 O si ṣe li ọjọ́ wọnni, ti Mose dàgba,
o jade tọ̀ awọn arakọnrin rẹ̀ lọ, o si wò iṣẹ
wọn: o si ri ara Egipti kan o nlù Heberu
kan, ọkan ninu awọn arakọnrin rẹ̀.
12 O si wò ihin, o wò ọ̀hún, nigbati o si
ri pe, kò sí ẹnikan, o lù ara Egipti na pa, o
si bò o ninu yanrin.
13 Nigbati o si jade lọ ni ijọ́ keji, kiyesi
i, ọkọnrin meji ara Heberu mbá ara wọn
jà: o si wi fun ẹniti o firan si ẹnikeji rè pe,
Ẽṣe ti iwọ fi nlù ẹgbẹ rẹ?
14 On si wipe, Tali o fi ọ jẹ́ olori ati oni-
dajọ lori wa? iwọ fẹ́ pa mi bi o ti pa ara
Egipti? Mose si bẹ̀ru, o si wipe, Lõtọ ọ̀ran
yi di mimọ̀.
15 Nigbati Farao si gbọ́ ọ̀ran yi, o nwá
ọ̀na lati pa Mose. Ṣugbọn Mose sá kuro
niwaju Farao, o si ngbé ilẹ Midiani: o si
joko li ẹba kanga kan.
16 Njẹ alufa Midiani li ọmọbirin meje,
nwọn si wá, nwọn pọn omi, nwọn si kún
ọkọ̀ imumi lati fi omi fun agbo-ẹran baba
wọn.
17 Awọn oluṣọ-agutan si wá, nwọn si lé
wọn kuro: nigbana ni Mose dide duro, o

Digitized by Google

ràn wọn lọwọ, o si fi omi fun agbo-ẹran
wọn.
18 Nigbati nwọn si bọ̀dé ọdọ Reueli baba
wọn, o ni, Ètiri ti ẹnyin fi tète dé bẽ loni?
19 Nwọn si wipe, Ara Egipti kan li o
gbà wa lọwọ awọn oluṣọ-agutan, o si pọn
omi to fun wa pẹlu, o si fi fun agbo-ẹran.
20 O si wi fun awọn ọmọbirin rẹ̀ pe, Nibo
li o gbé wà? ẽṣe ti ẹnyin fi ọkọnrin na
silẹ? ẹ pè e ki o le wá ijẹun.
21 O si dùn mọ́ Mose lati ma bá ọkọnrin
na gbé: on si fi Sippora ọmọbirin rẹ̀ fun
Mose.
22 On si bí ọmọkọnrin kan fun u, o si sọ
orukọ rẹ̀ ni Gerṣomu: nitoriti o wipe, Emi
ti nṣe atipo ni ilẹ ajeji.
23 O si ṣe lẹhin ọjọ́ pupọ̀, ti ọba Egipti
kú: awọn ọmọ Israeli si ngbin nitori ìsin
na, nwọn si ke, igbe wọn si goke tọ̀ Ọlọrun
lọ nitori ìsin wọn.
24 Ọlọrun si gbọ́ irora wọn, Ọlọrun si
ranti majẹmu rẹ̀ pẹlu Abrahamu, pẹlu Isa-
aki, ati pẹlu Jakobu.
25 Ọlọrun si bojuwò awọn ọmọ Israeli,
Ọlọrun si mọ̀ ọ fun wọn.

ORI 3.

MOSE si nṣọ́ agbo-ẹran Jetro bàba aya rẹ̀,
alufa Midiani: o si dà agbo-ẹran na
lọ si apa ẹhin ijù, o si dé Horebu, oke
Ọlọrun.
2 Angeli OLUWA si farahàn a li aló iná
lati inu ãrin igbẹ́: on si wò, si kiyesi i, iná
njó igbẹ́, igbẹ́ na kò si run.
3 Mose si wipe, Njẹ emi o yipada si apa-
kan, emi o si wò iran nla yi, ẽṣe ti igbẹ́ yi
kò run.
4 Nigbati OLUWA ri pe, o yipada si apa-
kan lati wò o, Ọlọrun kọ si i lati inu ãrin
igbẹ́ na wá, o si wipe, Mose, Mose. On si
dahun pe, Emi niyi.
5 O si wipe, Máṣe sunmọ ihin: bọ́ salu-
bata rẹ kuro li ẹsẹ̀ rẹ, nitori ibiti iwọ gbé
duro si nì, ilẹ mimọ́ ni.
6 O si wipe, Emi li Ọlọrun baba rẹ,
Ọlọrun Abrahamu, Ọlọrun Isaaki, ati Ọlọ-
run Jakobu. Mose si pa oju rẹ̀ mọ́; nito-
riti o bẹ̀ru lati bojuwò Ọlọrun.
7 OLUWA si wipe, Nitõtọ emi ti ri ipọn-
ju awọn enia mi ti o wà ni Egipti, mo si
gbọ́ igbe wọn nitori awọn akoniṣiṣẹ wọn;
nitoriti mo mọ̀ ibanujẹ wọn;
8 Emi si sọkalẹ wa lati gbà wọn lọwọ
awọn ara Egipti, ati lati mú wọn goke ti ilẹ
na wá si ilẹ rere ati nla, si ilẹ ti nṣàn fun
wàra ati fun oyin; si ibi ti awọn ara Kena-
ani, ati ti awọn Hitti, ati ti awọn Amori,
ati ti awọn Perissi, ati ti awọn Hifi, ati ti
awọn Jebusi.
9 Njẹ nisisiyi, kiyesi i, igbe awọn ọmọ
Israeli dé ọdọ mi; emi si ti ri pẹlu, wahala
ti awọn ọba Egipti nwahala wọn.
10 Nitorina wá nisisiyi, emi o si rán ọ si
Farao, ki iwọ ki o le mú awọn enia mi,
awọn ọmọ Israeli, lati Egipti jade wá.
11 Mose si wi fun Ọlọrun pe, Tali emi,
ti emi o fi tọ̀ Farao lọ, ati ti emi o fi le mú
awọn ọmọ Israeli jade lati Egipti wá?
12 O si wipe, Nitõtọ emi o wà pẹlu rẹ;
eyi ni yio si ṣe àmi fun ọ pe, emi li o rán ọ:
nigbati iwọ ba mú awọn enia na lati Egipti
jade wá, ẹnyin o sìn Ọlọrun lori oke yi.
13 Mose si wi fun Ọlọrun pe, Kiyesi i,
nigbati mo ba dé ọdọ awọn ọmọ Israeli, ti
emi o si wi fun wọn pe, Ọlọrun awọn baba
nyin li o rán mi si nyin; ti nwọn o si bi mi
pe, Orukọ rẹ̀? kili emi o wi fun wọn?
14 Ọlọrun si wi fun Mose pe, EMI NI
ẸNITI O WÀ: o si wipe, Bayi ni ki o wi
fun awọn ọmọ Israeli pe, EMI NI li o rán
mi si nyin.
15 Ọlọrun si wi fun Mose pẹlu pe, Bayi
ni ki iwọ ki o wi fun awọn ọmọ Israeli;
OLUWA, Ọlọrun awọn baba nyin, Ọlọrun
Abrahamu, Ọlọrun Isaaki, ati Ọlọrun Jako-
bu, li o rán mi si nyin: eyi li orukọ mi ti-
tilai, eyi si ni iranti mi lati irandiran.
16 Lọ, ki o si kó awọn àgba Israeli jọ, ki
o si wi fun wọn pe, OLUWA, Ọlọrun awọn
baba nyin, Ọlọrun Abrahamu, ti Isaaki, ati
ti Jakobu, li o farahàn mi wipe, Lõtọ ni mo
ti bẹ̀ nyin wò, mo si ti ri ohun ti a nṣe si
nyin ni Egipti:
17 Emi si ti wipe, Emi o mú nyin goke
jade ninu ipọnju Egipti si ilẹ awọn ara
Kenaani, ati ti awọn Hitti, ati ti awọn
Amori, ati ti awọn Perissi, ati ti awọn Hifi,
ati ti awọn Jebusi, si ilẹ ti nṣàn fun wàra
ati fun oyin.
18 Nwọn o si fetisi ohùn rẹ: iwọ o si wá,
iwọ ati awọn àgba Israeli, sọdọ ọba Egipti,
ẹnyin o si wi fun u pe, OLUWA, Ọlọrun
awọn Heberu pade wa: jẹ ki a lọ nisisiyi,
awa bẹ̀ ọ, ni ìrin ijọ́ mẹta si ijù, ki awa ki
o le rubọ si OLUWA Ọlọrun wa.
19 Emi si mọ́ pe ọba Egipti ki yio jẹ ki
ẹnyin ki o lọ, ki tilẹ iṣe nipa ọwọ́ agbara.
20 Emi o si nà ọwọ́ mi, emi o si fi iṣẹ-
iyanu mi gbogbo kọlù Egipti ti emi o ṣe
lãrin rẹ̀: lẹhin eyinì li on o to jọwọ nyin
lọwọ lọ.
21 Emi o si fi ojurere fun awọn enia yi li

Digitized by Google

oju awọn ara Egipti: yio si ṣe, nigbati ẹnyin o lọ, enyin ki yio lọ li ofo:

22 Olukuluku obirin ni yio si bère ohun-èlo fadaka, ati ohun-èlo wurà, ati aṣọ, lọwọ aladugbo rẹ̀, ati lọwọ ẹniti o nṣe atipo ninu ile rẹ̀: ẹnyin o si fi wọn si ara awọn ọmọkọnrin nyin, ati si ara awọn ọmọbirin nyin: ẹnyin o si kó ẹrù awọn ara Egipti.

## ORI 4.

MOSE si dahùn o si wipe, Ṣugbọn kiyesi i, nwọn ki yio gbà mi gbọ́, bẽni nwọn ki yio fetisi ohùn mi: nitoriti nwọn o wipe, OLUWA kò farahàn ọ.

2 OLUWA si wi fun u pe, Kini wà li ọwọ́ rẹ nì? On si wipe, Ọpá ni.

3 O si wi fun u pe, Sọ ọ si ilẹ. On si sọ ọ si ilẹ, o si di ejò; Mose si sá kuro niwaju rẹ̀.

4 OLUWA si wi fun Mose pe, Nà ọwọ́ rẹ ki o si mú u ni ìru: (On si nà ọwọ́ rẹ̀, o si mú u, o si di ọpá si i li ọwọ́:)

5 Ki nwọn ki o le gbàgbọ́ pe, OLUWA, Ọlọrun awọn baba wọn, Ọlọrun Abrahamu, Ọlọrun Isaaki, ati Ọlọrun Jakobu, li o farahàn ọ.

6 OLUWA si tun wi fun u pe, Fi ọwọ́ rẹ bọ̀ àiya rẹ. O si fi ọwọ́ rẹ̀ bọ̀ àiya rẹ̀: nigbati o si fà a yọ jade, si kiyesi i, ọwọ́ rẹ̀ dẹtẹ, o fún bi ẹ̀gbọn owu.

7 O si wipe, Tun fi ọwọ́ rẹ bọ̀ àiya rẹ. (O si tun fi ọwọ́ rẹ̀ bọ̀ àiya rẹ̀; o si fà a yọ jade li àiya rẹ̀; si kiyesi i, o si pada bọ̀ bi ẹran ara rẹ̀.)

8 Yio si ṣe, bi nwọn kò ba gbà ọ gbọ́, ti nwọn kò si fetisi ohùn iṣẹ-àmi iṣaju, njẹ nwọn o gbà ohùn iṣẹ-àmi ikẹhin gbọ́.

9 Yio si ṣe, bi nwọn kò ba si gbà àmi mejeji yi gbọ́ pẹlu, ti nwọn kò si fetisi ohùn rẹ, njẹ ki iwọ ki o bù ninu omi odò nì, ki o si dà a si iyangbẹ ilẹ: omi na ti iwọ bù ninu odò yio di ẹ̀jẹ ni iyangbẹ ilẹ.

10 Mose si wi fun OLUWA pe, Oluwa, emi ki iṣe ẹni ọ̀rọ-sisọ nigba atijọ wá, tabi lati igbati o ti mbá iranṣẹ rẹ sọ̀rọ: ṣugbọn olohùn wuwo ni mi, ati alahọn wuwo.

11 OLUWA si wi fun u pe, Tali o dá ẹnu enia? tabi tali o dá odi, tabi aditi, tabi ariran, tabi afọju? Emi OLUWA ha kọ́?

12 Njẹ lọ nisisiyi, emi o si pẹlu ẹnu rẹ, emi o si kọ́ ọ li eyiti iwọ o wi.

13 On si wipe, Oluwa, emi bẹ̀ ọ, rán ẹniti iwọ o rán.

14 Inu OLUWA si ru si Mose, o si wipe, Aaroni arakọnrin rẹ ọmọ Lefi kò ha wà? Emi mọ̀ pe o le sọ̀rọ jọjọ. Ati pẹlu, kiyesi i, o si mbọ̀wá ipade rẹ: nigbati o ba si ri ọ, on o yọ̀ ninu ọkàn rẹ̀.

15 Iwọ o si sọ̀rọ fun u, iwọ o si fi ọ̀rọ si i li ẹnu: emi o si pẹlu ẹnu rẹ, ati pẹlu ẹnu rẹ̀, emi o si kọ́ nyin li eyiti ẹnyin o ṣe.

16 On ni yio si ma ṣe ogbifọ rẹ fun awọn enia: yio si ṣe, on o ma jẹ́ ẹnu fun ọ, iwọ o si ma jẹ́ bi Ọlọrun fun u.

17 Iwọ o si mú ọpá yi li ọwọ́ rẹ, eyiti iwọ o ma fi ṣe iṣẹ-àmi.

18 Mose si lọ, o si pada tọ̀ Jetro ana rẹ̀, o si wi fun u pe, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki nlọ ki emi si pada tọ̀ awọn arakọnrin mi ti o wà ni Egipti, ki emi ki o si wò bi nwọn wà li ãye sibẹ̀. Jetro si wi fun Mose pe, Mã lọ li alafia.

19 OLUWA si wi fun Mose ni Midiani pe, Lọ, pada si Egipti: nitori gbogbo enia ti nwá ẹmi rẹ ti kú tán.

20 Mose si mú aya rẹ̀ ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀, o si gbé wọn gùn kẹtẹkẹtẹ kan, o si pada si ilẹ Egipti: Mose si mú ọpá Ọlọrun na li ọwọ́ rẹ̀.

21 OLUWA si wi fun Mose pe, Nigbati iwọ ba dé Egipti, kiyesi i ki iwọ ki o ṣe gbogbo iṣẹ-iyanu, ti mo filé ọ lọwọ, niwaju Farao, ṣugbọn emi o mu àiya rẹ̀ le, ti ki yio fi jẹ ki awọn enia na ki o lọ.

22 Iwọ o si wi fun Farao pe, Bayi li OLUWA wi, Ọmọ mi ni Israeli, akọ́bi mi:

23 Emi si ti wi fun ọ pe, Jẹ ki ọmọ mi ki o lọ, ki o le ma sìn mi; iwọ si ti kọ̀ lati jẹ ki o lọ: kiyesi i, emi o pa ọmọ rẹ, ani akọ́bi rẹ.

24 O si ṣe li ọ̀na ninu ile-èro, li OLUWA pade rẹ̀, o si nwá ọ̀na lati pa a.

25 Nigbana ni Sippora mú okuta mimú, o si kọ ọmọ rẹ̀ ni ilà abẹ, o si sọ ọ si ẹsẹ̀ Mose, o si wipe, Ọkọ ẹlẹjẹ ni iwọ fun mi nitõtọ.

26 Bẹ̃li o jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ. Nigbana ni Sippora wipe, Ọkọ ẹlẹjẹ ni iwọ nitori ikọlà na.

27 OLUWA si wi fun Aaroni pe, Lọ si ijù lọ ipade Mose. On si lọ, o si pade rẹ̀ li oke Ọlọrun, o si fi ẹnu kò o li ẹnu.

28 Mose si sọ gbogbo ọ̀rọ OLUWA ti o rán a fun Aaroni, ati gbogbo aṣẹ iṣẹ-àmi ti o fi fun u.

29 Mose ati Aaroni si lọ, nwọn si kó gbogbo àgba awọn ọmọ Israeli jọ:

30 Aaroni si sọ gbogbo ọ̀rọ ti OLUWA ti sọ fun Mose, o si ṣe iṣẹ-àmi na li oju awọn enia na.

31 Awọn enia na si gbàgbọ́: nigbati nwọn si gbọ́ pe, OLUWA ti bẹ̀ awọn ọmọ

Digitized by Google

Israeli wò, ati pe o si ti ri ipọnju wọn, nigbana ni nwọn tẹ̀ ori wọn ba, nwon si sìn.

## ORI 5.

LẸHIN eyinì ni Mose ati Aaroni wọle, nwọn si wi fun Farao pe, Bayi li OLUWA Ọlọrun Israeli wi, Jẹ ki awọn enia mi ki o lọ, ki nwọn ki o le ṣe ajọ fun mi ni ijù.

2 Farao si wipe, Tali OLUWA, ti emi o fi gbà ohùn rẹ̀ gbọ́ lati jẹ ki Israeli ki o lọ? Emi kò mọ̀ OLUWA na, bẹ̃li emi ki yio jẹ ki Israeli ki o lọ.

3 Nwọn si wipe, Ọlọrun awọn Heberu li o pade wa: awa bẹ̀ ọ, jẹ ki a lọ ni ìrin ijọ́ mẹta si ijù, ki a si rubọ si OLUWA Ọlọrun wa; ki o má ba fi ajakalẹ-àrun tabi idà kọlù wa.

4 Ọba Egipti si wi fun wọn pe, Mose ati Aaroni, nitori kili ẹnyin ṣe dá awọn enia duro ninu iṣẹ wọn? ẹ lọ si iṣẹ nyin.

5 Farao si wipe, Kiyesi i awọn enia ilẹ yi pọ̀ju nisisiyi, enyin si mu wọn simi kuro ninu iṣẹ wọn.

6 Farao si paṣẹ li ọjọ́ na fun awọn akoniṣiṣẹ awọn enia, ati fun awọn olori wọn wipe,

7 Ẹnyin kò gbọdọ fun awọn enia na ni koriko mọ́ lati ma ṣe briki, bi ìgba atẹhinwá: jẹ ki nwọn ki o ma lọ ṣà koriko fun ara wọn.

8 Ati iye briki ti nwọn ti ima ṣe ni ìgba atẹhinwá, on ni ki ẹnyin bù fun wọn; ẹnyin kò gbọdọ ṣẹ nkan kù kuro nibẹ̀: nitoriti nwọn nṣe imẹlẹ; nitorina ni nwọn ṣe nke wipe, Jẹ ki a lọ rubọ si Ọlorun wa.

9 Ẹ jẹ ki iṣẹ ki o wuwo fun awọn ọkọnrin na, ki nwọn ki o le ma ṣe lãlã ninu rẹ̀; ẹ má si ṣe jẹ ki nwọn ki o fiyesi ọ̀rọ eke.

10 Awọn akoniṣiṣẹ enia na si jade, ati awọn olori wọn, nwọn si sọ fun awọn enia na, pe, Bayi ni Farao wipe, Emi ki yio fun nyin ni koriko mọ́.

11 Ẹ lọ, ẹ wá koriko nibiti ẹnyin gbé le ri i: ṣugbọn a ki yio ṣẹ nkan kù ninu iṣẹ nyin.

12 Bẹ̃li awọn enia na si tuka kiri ká gbogbo ilẹ Egipti lati ma ṣà idi koriko ni ipò koriko.

13 Awọn akoniṣiṣẹ lé wọn ni ire wipe, Ẹ ṣe iṣẹ nyin pé, iṣẹ ojojumọ́ nyin, bi igbati koriko mbẹ.

14 Ati awọn olori awọn ọmọ Israeli, ti awọn akoniṣiṣẹ Farao yàn lé wọn, li a nlù, ti a si mbilère pe, Ẽṣe ti ẹnyin kò ṣe iṣẹ nyin pé ni briki ṣiṣe li ana ati li oni, bi ìgba atẹhinwá?

15 Nigbana li awọn olori awọn ọmọ Israeli wá, nwọn si ke tọ̀ Farao wipe, Eṣe ti iwọ fi nṣe awọn iranṣẹ rẹ bayi?

16 A kò fi koriko fun awọn iranṣẹ rẹ, nwọn si nwi fun wa pe, Ẹ ṣe briki: si kiyesi i, a nlù awọn iranṣẹ rẹ; ṣugbọn lọwọ awọn enia rẹ li ẹbi wà.

17 Ṣugbọn on wipe, Ẹnyin ọlẹ, ẹnyin ọlẹ: nitorina li ẹ ṣe wipe, Jẹ ki a lọ ṣẹbọ si OLUWA.

18 Njẹ ẹ lọ nisisiyi, ẹ ṣiṣẹ; a ki yio sá fi koriko fun nyin, sibẹ̀ iye briki nyin yio pé.

19 Awọn olori awọn ọmọ Israeli si ri pe, ọ̀ran wọn kò li oju, lẹhin igbati a wipe, Ẹ ki o dinkù ninu iye briki nyin ojojumọ́.

20 Nwọn si bá Mose on Aaroni, ẹniti o duro lati pade wọn bi nwọn ti nti ọdọ Farao jade wá:

21 Nwọn si wi fun wọn pe, Ki OLUWA ki o wò nyin, ki o si ṣe idajọ; nitoriti ẹnyin mu wa di okú-õrùn li oju Farao, ati li oju awọn iranṣẹ rẹ̀, lati fi idá lé wọn lọwọ lati pa wa.

22 Mose si pada tọ̀ OLUWA lọ, o si wi fun u pe, OLUWA, ẽtiṣe ti o fi ṣe buburu si awọn enia yi bẹ̃? ẽtiṣe ti o fi rán mi?

23 Nitori igbati mo ti tọ̀ Farao wá lati sọ̀rọ li orukọ rẹ, buburu li o ti nṣe si awọn enia yi; bẹ̃ni ni gbigbà iwọ kò si gbà awọn enia rẹ.

## ORI 6.

NIGBANA li OLUWA wi fun Mose pe, Nigbayi ni iwọ o ri ohun ti emi o ṣe si Farao: nitori ọwọ́ agbara li on o ṣe jọwọ wọn lọwọ lọ, ati pẹlu ọwọ́ agbara li on o fi tì wọn jade kuro ni ilẹ rẹ̀.

2 Ọlọrun si sọ fun Mose, o si wi fun u pe, Emi ni JEHOFAH:

3 Emi si farahàn Abrahamu, Isaaki, ati Jakobu, li Ọlọrun Olodumare, ṣugbọn orukọ mi JEHOFA, ni nwọn kò fi mọ̀ mi.

4 Emi si ti bá wọn da majẹmu mi pẹlu, lati fun wọn ni ilẹ Kenaani, ilẹ atipo wọn, nibiti nwọn gbé ṣe atipo.

5 Emi si ti gbọ́ irora awọn ọmọ Israeli pẹlu, ti awọn ara Egipti nmu sìn; emi si ti ranti majemu mi.

6 Nitorina wi fun awọn ọmọ Israeli pe, Emi li OLUWA, emi o si mú nyin jade kuro labẹ ẹrù awọn ara Egipti, emi o si yọ nyin kuro li oko-ẹrú wọn, emi o si fi apa ninà ati idajọ nla da nyin ni ìde:

7 Emi o si gbà nyin ṣe enia fun ara mi,

Digitized by Google

emi o si jẹ́ Ọlọrun fun nyin : ẹnyin o si mọ̀
pe emi li OLUWA Ọlọrun nyin, ti o mú nyin
jade kuro labẹ ẹrù awọn ara Egipti.
8 Emi o si mú nyin lọ sinu ilẹ na, ti mo
ti bura lati fi fun Abrahamu, fun Isaaki,
ati fun Jakobu ; emi o si fi i fun nyin ni
iní : Emi li OLUWA.
9 Mose si sọ bẽ fun awọn ọmọ Israeli:
ṣugbọn nwọn kò gbà ti Mose gbọ́ fun
ibinujẹ ọkàn, ati fun ìsin lile.
10 OLUWA si sọ fun Mose pe,
11 Wọle, sọ fun Farao ọba Egipti pe, ki
o jẹ ki awọn ọmọ Israeli ki o lọ kuro ni ilẹ
rẹ̀.
12 Mose si sọ niwaju OLUWA wipe, Ki-
yesi i, awọn ọmọ Israeli kò gbọ́ ti emi,
Farao yio ha ti ṣe gbọ́ ti emi, emi ẹniti iṣe
alaikọlà ète ?
13 OLUWA si bá Mose ati Aaroni sọ̀rọ, o
si fi aṣẹ fun wọn si awọn ọmọ Israeli, ati si
Farao, ọba Egipti, lati mú awọn ọmọ Isra-
eli jade ni ilẹ Egipti.
14 Wọnyi li olori ile baba wọn : awọn
ọmọ Reubeni akọ́bi Israeli ; Hanoku, ati
Pallu, Hesroni, ati Karmi : wọnyi ni idile
Reubeni.
15 Ati awọn ọmọ Simeoni ; Jemueli, ati
Jamini, ati Ohadi, ati Jakini, ati Sohari,
ati Ṣaulu ọmọ obirin ara Kénaani ; wọnyi
ni idile Simeoni.
16 Wọnyi si li orukọ awọn ọmọ Lefi ni
iran wọn ; Gerṣoni, ati Kohati, ati Merari :
ọdún aiye Lefi si jẹ́ mẹtadilogoje.
17 Awọn ọmọ Gerṣoni ; Libni, ati Ṣimei,
ni idile wọn.
18 Ati awọn ọmọ Kohati ; Amramu ati
Iṣhari, ati Hebroni, ati Ussieli ọdún aiye
Kohati si jẹ́ ãdoje o le mẹta.
19 Ati awọn ọmọ Merari ; Mahali, ati
Muṣi. Wọnyi ni idile Lefi ni iran wọn.
20 Amramu si fẹ́ Jokebedi arabirin baba
rẹ̀ li aya, on li o si bí Aaroni ati Mose fun
u : ọdún aiye Amramu si jẹ́ mẹtadilogoje.
21 Ati awọn ọmọ Iṣhari ; Kora, ati Ne-
fegi, ati Sikri.
22 Ati awọn ọmọ Ussieli ; Miṣaeli, ati
Elsafani, ati Sitri.
23 Aaroni si fẹ́ Eliṣeba, ọmọbirin Ami-
nadabu, arabirin Naṣoni, li aya ; on si bí
Nadabu ati Abihu, Eleasari, ati Itamari
fun u.
24 Ati awọn ọmọ Kora ; Assiri, ati
Elkana, ati Abiasafu ; wọnyi ni idile awọn
ọmọ Kora.
25 Eleasari ọmọ Aaroni si fẹ́ ọkan ninu
awọn ọmọbirin Putieli li aya ; on si bí Fi-
nehasi fun u : wọnyi li olori awọn baba
awọn ọmọ Lefi ni idile wọn.
26 Wọnyi ni Aaroni on Mose na, ẹniti
OLUWA sọ fun pe, Ẹ mú awọn ọmọ Israeli
jade kuro ni ilẹ Egipti, gẹgẹ bi ogun wọn.
27 Awọn wọnyi li o bá Farao ọba Egipti
sọ̀rọ lati mú awọn ọmọ Israeli jade kuro ni
Egipti : wọnyi ni Mose ati Aaroni na.
28 O si ṣe li ọjọ́ ti OLUWA bá Mose sọ̀rọ
ni ilẹ Egipti,
29 Ni OLUWA sọ fun Mose wipe, Emi li
OLUWA : sọ gbogbo eyiti mo wi fun ọ fun
Farao ọba Egipti.
30 Mose si wi niwaju OLUWA pe, Kiyesi
i, alaikọlà ète li emi, Farao yio ha ti ṣe fe-
tisi ti emi ?

## ORI 7.

OLUWA si wi fun Mose pe, Wò o, emi fi
ọ ṣe ọlọrun fun Farao : Aaroni arakọn-
rin rẹ ni yio si ma ṣe woli rẹ.
2 Iwọ o sọ gbogbo eyiti mo palaṣẹ fun
ọ : Aaroni arakọnrin rẹ ni yio si ma sọ
fun Farao pe, ki o rán awọn ọmọ Israeli
jade ni ilẹ rẹ̀.
3 Emi o si mu Farao li àiya le, emi o si
sọ iṣẹ-àmi mi ati iṣẹ-iyanu mi di pupọ̀ ni
ilẹ Egipti.
4 Ṣugbọn Farao ki yio gbọ́ ti nyin, emi
o si fi ọwọ́ mi lé Egipti, emi o si fi idajọ nla
mú awọn ogun mi, ani awọn ọmọ Israeli
enia mi, jade kuro ni ilẹ Egipti.
5 Awọn ara Egipti yio si mọ̀ pe, emi li
OLUWA, nigbati mo ba nà ọwọ́ mi lé Egip-
ti, ti mo si mú awọn ọmọ Israeli jade kuro
lãrin wọn.
6 Mose ati Aaroni si ṣe bẽ ; bi OLUWA
ti paṣẹ fun wọn ; bẽni nwọn ṣe.
7 Mose jẹ́ ẹni ọgọrin ọdún, Aaroni si jẹ́
ẹni ọgọrin ọdún o le mẹta, nigbati nwọn
sọ̀rọ fun Farao.
8 OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni
pe,
9 Nigbati Farao yio ba wi fun nyin pe,
Ẹ fi iṣẹ-iyanu kan hàn : nigbana ni ki iwọ
ki o wi fun Aaroni pe, Mú ọpá rẹ, ki o si
fi i lelẹ̀ niwaju Farao, yio si di ejò.
10 Mose ati Aaroni si wọle tọ̀ Farao lọ,
nwọn si ṣe bi OLUWA ti paṣẹ fun wọn :
Aaroni si fi ọpá rẹ̀ lelẹ niwaju Farao ati
niwaju awọn iranṣẹ rẹ̀, o si di ejò.
11 Nigbana ni Farao pẹlu pè awọn ọlọ-
gbọ́n ati awọn oṣó : awọn pẹlu, ani awọn
alalupayida Egipti, si fi idán wọn ṣe bẽ
gẹgẹ.
12 Nitoriti olukuluku nwọn fi ọpá rẹ̀

Digitized by Google

lelẹ, nwọn si di ejò: ṣugbọn ọpá Aaroni
gbe ọpá wọn mì.
13 Aiya Farao si le, kò si fetisi ti wọn;
bi OLUWA ti wi.
14 OLUWA si wi fun Mose pe, Aiya Fa-
rao di lile, o kọ̀ lati jẹ ki awọn enia na ki
o lọ.
15 Tọ̀ Farao lọ li owurọ̀; kiyesi i, o
njade lọ si odò; ki iwọ ki o si duro lati
pade rẹ̀ leti odò; ati ọpá nì ti o di ejò ni
ki iwọ ki o mú li ọwọ́ rẹ.
16 Iwọ o si wi fun u pe, OLUWA, Ọlọrun
awọn Heberu, li o rán mi si ọ wipe, Jẹ ki
awọn enia mi ki o lọ, ki nwọn ki o le sìn
mi ni ijù: si kiyesi i, titi di isisiyi iwọ kò
gbọ́.
17 Bayi li OLUWA wi, Ninu eyi ni iwọ
o fi mọ̀ pe emi li OLUWA: kiyesi i, emi o
fi ọpá ti o wà li ọwọ́ mi lù omi ti o wà li
odò, nwọn o si di ẹ̀jẹ.
18 Ẹja ti o wà ninu odò na yio si kú,
odò na yio si ma rùn; awon ara Egipti yio
si korira ati ma mu ninu omi odò na.
19 OLUWA si sọ fun Mose pe, Wi fun
Aaroni pe, Mú ọpá rẹ, ki o si nà ọwọ́ rẹ si
oju omi Egipti wọnni, si odò wọn, si omi
ṣiṣàn wọn, ati ikudu wọn, ati si gbogbo
ikojọpọ omi wọn, ki nwọn le di ẹ̀jẹ; ẹ̀jẹ
yio si wà ni gbogbo ilẹ Egipti, ati ninu
ohun-èlo igi, ati ninu ohun-èlo okuta.
20 Mose ati Aaroni si ṣe bẹ̃ bi OLUWA ti
fi aṣẹ fun wọn; o si gbé ọpá na soke o si lù
omi ti o wà li odò li oju Farao, ati li oju
awọn iranṣẹ rẹ̀; a si sọ gbogbo omi ti o wà
li odò na di ẹ̀jẹ.
21 Ẹja ti o wà li odò si kú; odò na si
nrùn, awọn ara Egipti kò si le mu ninu
omi odò na; ẹ̀jẹ si wà ni gbogbo ilẹ Egipti,
22 Awọn alalupayida Egipti si fi idán
wọn ṣe bẹ̃: àiya Farao si le, bẹ̃ni kò si
fetisi ti wọn; bi OLUWA ti wi.
23 Farao si pada o lọ si ile rẹ̀, kò si fi ọ-
kàn rẹ̀ si eyi pẹlu.
24 Gbogbo awọn ara Egipti si wàlẹ yi
odò na ká fun omi mimu; nitoriti nwọn
kò le mu ninu omi na.
25 Ọjọ́ meje si pé, lẹhin igbati OLUWA
lù odò na.

## ORI 8.

OLUWA si sọ fun Mose pe, Tọ̀ Farao lọ,
ki o si wi fun u pe, Bayi li OLUWA
wipe, Jẹ ki awọn enia mi ki o lọ, ki nwọn
ki o le sìn mi.
2 Bi iwọ ba si kọ̀ lati jẹ ki nwọn ki o lọ,
kiyesi i, emi o fi ọpọlọ kọlù gbogbo ẹ-
kùn rẹ:
3 Odò yio si bí ọpọlọ jade li ọ̀pọlọpọ,
nwọn o si goke, nwọn o si wá sinu ile rẹ,
ati sinu ibusun rẹ, ati sori akete rẹ, ati si-
nu ile awọn ọmọ-ọdọ rẹ, ati sara awọn enia
rẹ, ati sinu ãro rẹ, ati sinu ọpọ́n ìpo-iyẹfun
rẹ:
4 Awọn ọpọlọ na yio si gùn ọ lara, ati
lara awọn enia rẹ, ati lara gbogbo awọn
iranṣẹ rẹ.
5 OLUWA si sọ fun Mose pe, Wi fun
Aaroni pe, Nà ọwọ́ rẹ pẹlu ọpá rẹ sori odò
wọnni, sori omi ṣiṣàn, ati sori ikojọpọ̀ omi,
ki o si mú ọpọlọ jade wá sori ilẹ Egipti.
6 Aaroni si nà ọwọ́ rẹ̀ sori omi Egipti;
awọn ọpọlọ si goke wá, nwọn si bò ilẹ
Egipti.
7 Awọn alalupayida si fi idán wọn ṣe bẹ̃,
nwọn si mú ọpọlọ jade wá sori ilẹ Egipti.
8 Nigbana ni Farao pè Mose ati Aaroni,
o si wipe, Ẹ bẹ̀ OLUWA, ki o le mú awọn
ọpọlọ kuro lọdọ mi, ati kuro lọdọ awọn
enia mi; emi o si jẹ ki awọn enia na ki o
lọ, ki nwọn ki o le ṣẹbọ si OLUWA.
9 Mose si wi fun Farao pe, Paṣẹ fun
mi: nigbawo li emi o bẹ̀bẹ fun ọ, ati fun
awọn iranṣẹ rẹ, ati fun awọn enia rẹ, lati
run awọn ọpọlọ kuro lọdọ rẹ, ati kuro ninu
ile rẹ, ki nwọn ki o kù ni kìki odò nikan?
10 On si wipe, Li ola. O si wipe, Ki o
ri bi ọ̀rọ rẹ; ki iwo ki o le mọ̀ pe, kò sí
ẹniti o dabi OLUWA Ọlọrun wa.
11 Awọn ọpọlọ yio si lọ kuro lọdọ rẹ,
ati kuro ninu ile rẹ, ati kuro lọdọ awọn
iranṣẹ rẹ, ati kuro lọdọ awọn enia re; ni
kìki odò ni nwọn o kù si.
12 Mose ati Aaroni si jade kuro lọdọ
Farao: Mose si kigbe si OLUWA nitori
ọpọlọ ti o ti múwa si ara Farao.
13 OLUWA si ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ Mose; awọn
ọpọlọ na si kú kuro ninu ile, ninu agbalá,
ati kuro ninu oko.
14 Nwọn si kó wọn jọ li òkiti-òkiti: ilẹ
na si nrùn.
15 Ṣugbọn nigbati Farao ri pe afo wà, o
mu àiya rẹ̀ le, kò si fetisi ti wọn; bi OLU-
WA ti wi.
16 OLUWA si wi fun Mose pe, Sọ fun
Aaroni pe, Nà ọpá rẹ, ki o si lù ekuru ilẹ,
ki o le di iná já gbogbo ilẹ Egipti.
17 Nwọn si ṣe bẹ̃; Aaroni si nà ọwọ́ rẹ̀
pẹlu ọpá rẹ̀, o si lù erupẹ ilẹ, iná si wà lara
enia, ati lara ẹran; gbogbo ekuru ilẹ li o di
iná já gbogbo ilẹ Egipti.
18 Awọn alalupayida si fi idán wọn ṣe bẹ̃

Digitized by Google

lati mú iná jade wá, ṣugbọn nwọn kò le ṣe e: bẽni iná si wà lara enia, ati lara ẹran.

19 Nigbana ni awọn alalupayida wi fun Farao pe, Ika Ọlọrun li eyi: ṣugbọn àiya Farao le, kò si fetisi ti wọn; bi OLUWA ti wi.

20 OLUWA si wi fun Mose pe, Dide ni kutukutu owurọ̀, ki o si duro niwaju Farao; kiyesi i, o njade lọ si odò; ki o si wi fun u pe, Bayi li OLUWA wi, Jẹ ki awọn enia mi ki o lọ, ki nwọn ki o le sìn mi.

21 Bi iwọ kò ba si jẹ ki awọn enia mi ki o lọ, kiyesi i, emi o rán ọwọ́ eṣinṣin si ọ, ati sara iranṣẹ rẹ, ati sara awọn enia rẹ, ati sinu awọn ile rẹ: gbogbo ile awọn ara Egipti ni yio si kún fun ọwọ́ eṣinṣin, ati ilẹ ti nwọn gbé wà pẹlu.

22 Li ọjọ́ na li emi o yà ilẹ Goṣeni sọ̀tọ, ninu eyiti awọn enia mi tẹ̀dó si, ti eṣinṣin ki yio sí nibẹ̀; nitori ki iwọ ki o le mọ̀ pe, emi li OLUWA lãrin ilẹ-aiye.

23 Emi o si pàla si agdedemeji awọn enia mi ati awon enia rẹ: li ọla ni iṣẹ-àmi yi yio si wà.

24 OLUWA si ṣe bẽ; ọwọ́ eṣinṣin ọ̀pọlọpọ si dé sinu ile Farao, ati sinu ile awọn iranṣẹ rẹ̀: ati ni gbogbo ilẹ Egipti, ilẹ na bàjẹ́ nitori ọwọ́ eṣinṣin wọnni.

25 Farao si ranṣẹ pè Mose ati Aaroni o si wipe; Ẹ ma lọ ṣẹbọ si Ọlọrun nyin ni ilẹ yi.

26 Mose si wipe, Kò tọ́ lati ṣe bẽ; nitori awa o fi ohun irira awọn ara Egipti rubọ si OLUWA Ọlọrun wa: wò o, awa le fi ohun irira awọn ara Egipti rubọ li oju wọn, nwọn ki yio ha sọ wa li okuta?

27 Awa o lọ ni ìrin ijọ́ mẹta sinu ijù, ki a si rubọ si OLUWA Ọlọrun wa, bi on o ti paṣẹ fun wa.

28 Farao si wipe, Emi o jẹ ki ẹnyin lọ, ki ẹ le rubọ si OLUWA Ọlọrun nyin ni ijù; kìki ki ẹnyin ki o máṣe lọ jìna jù: ẹ bẹ̀bẹ fun mi.

29 Mose si wipe, Kiyesi i, emi njade lọ kuro lọdọ rẹ, emi o si bẹ̀ OLUWA ki ọwọ́ eṣinṣin wọnyi ki o le ṣí kuro lọdọ Farao, kuro lọdọ awọn iranṣẹ rẹ̀, ati kuro lọdọ awọn enia rẹ̀, li ọla: kìki ki Farao ki o máṣe ẹ̀tan mọ́ li aijẹ ki awọn enia na ki o lọ rubọ si OLUWA.

30 Mose si jade kuro lọdọ Farao, o si bẹ̀ OLUWA.

31 OLUWA si ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ Mose; o si ṣí ọwọ́ eṣinṣin na kuro lọdọ Farao, ati kuro lọdọ awọn iranṣẹ rẹ̀, ati kuro lọdọ awọn enia rẹ̀; ọkan kò kù.

32 Farao si mu àiya rẹ̀ le nigbayi pẹlu, kò si jẹ ki awọn enia na ki o lọ.

## ORI 9.

NIGBANA li OLUWA wi fun Mose pe, Wọle tọ̀ Farao lọ ki o si wi fun u pe, Bayi li OLUWA, Ọlọrun awọn Heberu wi, Jẹ ki awọn enia mi ki o lọ, ki nwọn le sìn mi.

2 Nitoripe, bi iwọ ba kọ̀ lati jẹ ki nwọn lọ, ti iwọ si da wọn duro sibẹ̀,

3 Kiyesi i, ọwọ́ OLUWA mbẹ lara ẹran-ọ̀sin rẹ ti mbẹ li oko, lara ẹṣin, lara kẹtẹkẹtẹ, lara ibakasiẹ, lara ọwọ́-malu, ati lara agbo-agutan wọnni: ajakalẹ-àrun buburu mbọ̀.

4 OLUWA yio si pàla si agbedemeji ẹran-ọ̀sin Israeli ati ẹran-ọ̀sin Egipti: kò sí ohun kan ti yio kú ninu gbogbo eyiti iṣe ti awọn ọmọ Israeli.

5 OLUWA si dá akokò kan wipe, Li ọla li OLUWA yio ṣe nkan yi ni ilẹ yi.

6 OLUWA si ṣe nkan na ni ijọ́ keji, gbogbo ẹran-ọ̀sin Egipti si kú: ṣugbọn ninu ẹran-ọ̀sin awọn ọmọ Israeli ọkanṣoṣo kò si kú.

7 Farao si ranṣẹ, si kiyesi i, ọkanṣoṣo kò kú ninu ẹran-ọ̀sin awon ọmọ Israeli. Àiya Farao si le, kò si jẹ ki awọn enia na ki o lọ.

8 OLUWA si wi fun Mose ati fun Aaroni pe, Bù ikunwọ ẽru ninu ileru, ki Mose ki o kù u si oju-ọrun li oju Farao.

9 Yio si di ekuru lẹbulẹbu ni gbogbo ilẹ Egipti, yio si di õwo ti yio ma tú pẹlu ileròro lara enia, ati lara ẹran, ká gbogbo ilẹ Egipti.

10 Nwọn si bù ẽru ninu ileru, nwọn duro niwaju Farao; Mose si kù u si oke ọrun; o si di õwo ti o ntú jade pẹlu ileròro lara enia ati lara ẹran.

11 Awon alalupayida kò si le duro niwaju Mose nitori õwo wọnni; nitoriti õwo na wà lara awọn alalupayida, ati lara gbogbo awọn ara Egipti.

12 OLUWA si mu àiya Farao le, kò si gbọ́ ti wọn; bi OLUWA ti sọ fun Mose.

13 OLUWA si wi fun Mose pe, Dide ni kutukutu owurọ̀, ki o si duro niwaju Farao, ki o si wi fun u pe, Bayi li OLUWA, Ọlọrun awọn Heberu wi, Jẹ ki awọn enia mi ki o lọ ki nwọn le sìn mi.

14 Nitori ìgba yi li emi o rán gbogbo iyọnu mi si àiya rẹ, ati sara awọn iranṣẹ rẹ, ati sara awọn enia rẹ; ki iwọ ki o le mọ̀ pe kò sí ẹlomiran bi emi ni gbogbo aiye.

15 Nitori nisisiyi, emi iba nà ọwọ́ mi, ki

Digitized by Google

emi ki o le fi ajakalẹ-àrun lù ọ, ati awọn
enia rẹ; a ba si ti ke ọ kuro lori ilẹ.
16 Ṣugbọn nitori eyi pāpa li emi ṣe mu ọ
duro, lati fi agbara mi hàn lara rẹ; ati ki
a le ròhin orukọ mi ká gbogbo aiye.
17 Titi di isisiyi iwọ ngbé ara rẹ ga si
awọn enia mi pe, iwọ ki yio jẹ ki nwọn ki o
lọ?
18 Kiyesi i, li ọla li akokò yi, li emi o
mu ọ̀pọ yinyin rọ̀ si ilẹ, irú eyiti kò ti sí ni
Egipti lati ipilẹṣẹ rẹ̀ titi o fi di isisiyi.
19 Njẹ nisisiyi ranṣẹ ki o si kó ẹran rẹ
bọ̀, ati ohun gbogbo ti o ní ninu oko; ni-
tori olukuluku enia ati ẹran ti a ba ri li
oko, ti a kò si múbọ̀ wá ile, yinyin yio bọ
lù wọn, nwọn o si kú.
20 Ẹniti o bẹ̀ru ọ̀rọ OLUWA ninu awọn
iranṣẹ Farao, mu ki awọn iranṣẹ rẹ̀ ati awọn
ẹran-ọ̀sin rẹ̀ sábọ̀ wá ile:
21 Ẹniti kò si kà ọ̀rọ OLUWA si, jọwọ
awọn iranṣẹ rẹ̀ ati awọn ẹran-ọ̀sin rẹ̀ si oko.
22 OLUWA si sọ fun Mose pe, Nà ọwọ́
rẹ si oke ọrun, ki yinyin ki o le bọ́ si gbo-
gbo ilẹ Egipti, sara enia, ati sara ẹranko,
ati sara eweko igbẹ́ gbogbo, já gbogbo ilẹ
Egipti.
23 Mose si nà ọpá rẹ̀ si ọrun: OLUWA
si rán ãra ati yinyin, iná na si njó lori ilẹ;
OLUWA si rọ̀ yinyin sori ilẹ Egipti.
24 Yinyin si bọ́, iná si dàpọ mọ́ yinyin
na, o papọ̀ju, irú rẹ̀ kò sí rí ni gbogbo ilẹ
Egipti lati igba ti o ti di orilẹ-ède.
25 Yinyin na si lù ohun gbogbo ti o wà
ninu oko bolẹ, ati enia ati ẹranko, já gbo-
gbo ilẹ Egipti; yinyin na si lù gbogbo ewe-
ko bolẹ, o si fà gbogbo igi igbẹ́ ya.
26 Ni kìki ilẹ Goṣeni, nibiti awọn ọmọ
Israeli gbé wà, ni yinyin kò sí.
27 Farao si ranṣẹ, o si pè Mose ati Aaroni,
o si wi fun wọn pe, Emi ṣẹ̀ nigbayi: OLUWA
li olododo, ẹni buburu si li emi ati awọn
enia mi.
28 Ẹ bẹ̀ OLUWA (o sa to) ki ãra nla ati
yinyin wọnyi ki o máṣe sí mọ́; emi o si jẹ
ki ẹ ma lọ; ẹ ki yio si duro mọ́.
29 Mose si wi fun u pe, Bi mo ba ti jade
ni ilu, emi o tẹ́ ọwọ́ mi si OLUWA; ãra yio
si dá, bẹ̃ni yinyin ki yio sí mọ́; ki iwọ ki
o le mọ̀ pe ti OLUWA li aiye.
30 Ṣugbọn bi o ṣe tirẹ ni ati ti awọn
iranṣẹ rẹ, emi mọ̀ pe sibẹ, ẹnyin kò ti ibẹ̀ru
OLUWA Ọlọrun.
31 A si lù ọgbọ́ ati ọkà barle bolẹ; ni-
tori ọkà barle wá ni ipẹ́, ọgbọ́ si rudi.
32 Ṣugbọn alikama ati ọkà (rie) li a kò
lù bolẹ: nitoriti nwọn kò ti idàgba.
33 Mose si jade kuro lọdọ Farao sẹhin
ilu, o si tẹ́ ọwọ́ rẹ̀ si OLUWA; ãra ati yin-
yin si dá, bẹ̃li òjo kò si rọ̀ si ilẹ mọ́.
34 Nigbati Farao ri pe, òjo ati yinyin
ati ãra dá, o ṣẹ̀ si i, o si sé àiya rẹ̀ le, on ati
awọn iranṣẹ rẹ̀.
35 Àiya Farao si le, bẹ̃ni kò si jẹ ki awọn
ọmọ Israeli ki o lọ; bi OLUWA ti wi lati
ọwọ́ Mose.

## ORI 10.

OLUWA si sọ fun Mose pe, Wọle tọ̀ Farao
lọ: nitoriti mo mu àiya rẹ̀ le, ati àiya
awọn iranṣẹ rẹ̀, ki emi ki o le fi iṣẹ-àmi mi
wọnyi hàn niwaju rẹ̀:
2 Ati ki iwọ ki o le wi li eti ọmọ rẹ, ati
ti ọmọ ọmọ rẹ, ohun ti mo ṣe ni Egipti, ati
iṣẹ-àmi mi ti mo ṣe ninu wọn; ki ẹnyin ki
o le mọ̀ pe emi li OLUWA.
3 Mose ati Aaroni si wọle tọ̀ Farao lọ,
nwọn si wi fun u pe, Bayi li OLUWA Ọlọrun
Heberu wi, Iwọ o ti kọ̀ pẹ tó lati rẹ̀ ara rẹ
silẹ niwaju mi? jẹ ki awọn enia mi ki o lọ,
ki nwọn ki o le sìn mi.
4 Ṣugbọn bi iwọ ba si kọ̀ lati jẹ ki awọn
enia mi ki o lọ, kiyesi i, li ọla li emi o mú
eṣú wá si ẹkùn rẹ:
5 Nwọn o si bò oju ilẹ ti ẹnikan ki yio
fi le ri ilẹ: nwọn o si jẹ ajẹkù eyiti o bọ́,
ti o kù fun nyin lọwọ yinyin, yio si jẹ igi
nyin gbogbo ti o nruwe ninu oko.
6 Nwọn o si kún ile rẹ, ati ile awọn iran-
ṣẹ rẹ gbogbo, ati ile awọn ara Egipti gbo-
gbo; ti awọn baba rẹ, ati awọn baba baba
rẹ kò ri rí, lati igba ọjọ́ ti nwọn ti wà lori
ilẹ titi o fi di oni-oloni. O si yipada, o jade
kuro lọdọ Farao.
7 Awọn iranṣẹ Farao si wi fun u pe,
Ọkọnrin yi yio ti ṣe ikẹkùn si wa pẹ to?
jẹ ki awọn ọkọnrin na ki o lọ, ki nwọn ki
o le sìn OLUWA Ọlọrun wọn: iwọ kò ti
imọ̀ pe Egipti run tán?
8 A si tun mú Mose ati Aaroni wá sọdọ
Farao: o si wi fun wọn pe, Ẹ lọ sìn OLUWA
Ọlọrun nyin; ṣugbọn awọn tani yio ha lọ?
9 Mose si wipe, Awa o lọ ati ewe ati àgba,
ati awọn ọmọkọnrin wa ati awọn ọmọbirin
wa, pẹlu awọn agbo, ati ọwọ́-ẹran wa li awa
o lọ; nitori ajọ OLUWA ni fun wa.
10 O si wi fun wọn pe, Ki OLUWA ki o
pẹlu nyin bẹ̃, bi emi o ti jẹ ki ẹ lọ yi, ati
awọn ewe nyin: ẹ wò o; nitori ibi mbẹ
niwaju nyin.
11 Bẹ̃kọ: ẹnyin ọkọnrin ẹ lọ, ki ẹ si sìn
OLUWA; eyini li ẹnyin sá nfẹ́. Nwọn si
lé wọn jade kuro niwaju Farao.

Digitized by Google

12 OLUWA si wi fun Mose pe, Nà ọwọ́ rẹ sori ilẹ Egipti nitori eṣú, ki nwọn ki o le wá sori ilẹ Egipti, ki nwọn ki o si le jẹ gbogbo eweko ilẹ yi, gbogbo eyiti yinyin ti kù silẹ.

13 Mose si nà ọpá rẹ̀ si ori ilẹ Egipti, OLUWA si mu afẹfẹ ìla-õrùn kan fẹ́ si ori ilẹ na, ni gbogbo ọsán na, ati gbogbo oru na; nigbati o di owurọ̀, afẹfẹ ìla-õrùn mú awọn ẽṣú na wá.

14 Awọn eṣú na si goke sori ilẹ Egipti gbogbo, nwọn si bà si ẹkùn Egipti gbogbo; nwọn papọ̀ju, kò sí irú eṣú bẹ̃ ṣaju wọn, bẽni lẹhin wọn irú wọn ki yio si sí.

15 Nitoriti nwọn bò oju ilẹ gbogbo, tobẹ ti ilẹ fi ṣú; nwọn si jẹ gbogbo eweko ilẹ na, ati gbogbo eso igi ti yinyin kù silẹ: kò si kù ohun tutù kan lara igi, tabi lara eweko igbẹ́, já gbogbo ilẹ Egipti.

16 Nigbana ni Farao ranṣẹ pè Mose ati Aaroni kánkan; o si wipe, Emi ti ṣẹ̀ si OLUWA Ọlọrun nyin, ati si nyin.

17 Njẹ nitorina emi bẹ̀ nyin, ẹ fi ẹ̀ṣẹ mi jì lẽkanṣoṣo yi, ki ẹ si bẹ̀ OLUWA Ọlọrun nyin, ki o le mú ikú yi kuro lọdọ mi.

18 On si jade kuro niwaju Farao, o si bẹ̀ OLUWA.

19 OLUWA si yi afẹfẹ ìwọ-õrùn lilelile ti o si fẹ́ awọn eṣú na kuro, o si gbá wọn lọ sinu Okun Pupa; kò si kù eṣú kanṣoṣo ni gbogbo ẹkùn Egipti.

20 Ṣugbọn OLUWA mu àiya Farao le, bẽni kò si jẹ ki awọn ọmọ Israeli ki o lọ.

21 OLUWA si wi fun Mose pe, Nà ọwọ́ rẹ si ọrun, ki òkunkun ki o ṣú yiká ilẹ Egipti, ani òkunkun ti a le fọwọbà.

22 Mose si nà ọwọ́ rẹ̀ si ọrun: òkunkun biribiri si ṣú ni gbogbo ilẹ Egipti ni ijọ́ mẹta:

23 Nwọn kò ri ara wọn, bẽli ẹnikan kò si dide ni ipò tirẹ̀ ni ijọ́ mẹta: ṣugbọn gbogbo awọn ọmọ Israeli li o ní imọle ni ibugbé wọn.

24 Farao si pè Mose, o si wipe, Ẹ ma lọ, ẹ sìn OLUWA; kìki agbo ati ọwọ́-ẹran nyin ni ki o kù lẹhin; ki awọn ewe nyin ki o bá nyin lọ pẹlu.

25 Mose si wipe, Iwọ kò le ṣaima fun wa li ohun ẹbọ pẹlu ati ẹbọ sisun, ti awa o fi rubọ si OLUWA Ọlọrun wa.

26 Ẹran-ọ̀sin wa yio si bá wa lọ pẹlu; a ki yio fi ibósẹ-ẹran kan silẹ lẹhin; nitori ninu rẹ̀ li awa o mú sìn OLUWA Ọlọrun wa; awa kò si mọ̀ ohun na ti a o fi sìn OLUWA, titi awa o fi dé ibẹ̀.

27 Ṣugbọn OLUWA mu àiya Farao le, kò si fẹ́ jẹ ki nwọn lọ.

28 Farao si wi fun u pe, Kuro lọdọ mi, ma ṣọ́ ara rẹ, máṣe tun ri oju mi mọ́; nitori ni ijọ́ na ti iwọ ba ri oju mi iwọ o kú.

29 Mose si wipe, Iwọ fọ̀ rere; emi ki yio tun ri oju rẹ mọ́.

## ORI 11.

OLUWA si wi fun Mose pe, Emi o tun mú iyọnu kan wá sara Farao, ati sara Egipti; lẹhin eyinì ni on o jọwọ nyin lọwọ lọ lati ihin: nigbati on o jẹ ki ẹ lọ, àtitán ni yio tì nyin jade nihin.

2 Wi nisisiyi li eti awọn enia wọnyi, ki olukuluku ọkọnrin ki o bère lọdọ aladugbo rẹ̀ ati olukuluku obirin lọdọ aladugbo rẹ̀, ohun-èlo fadaka, ati ohun-èlo wurà.

3 OLUWA si fi ojurere fun awọn enia na li oju awọn ara Egipti. Pẹlupẹlu Mose ọkọnrin nì o pọ̀ gidigidi ni ilẹ Egipti, li oju awọn iranṣẹ Farao, ati li oju awọn enia na.

4 Mose si wipe, Bayi li OLUWA wi, Lãrin ọganjọ li emi o jade lọ sãrin Egipti:

5 Gbogbo awọn akọ́bi ti o wà ni ilẹ Egipti ni yio si kú, lati akọ́bi Farao lọ ti o joko lori itẹ́ rẹ̀, titi yio si fi dé akọ́bi iranṣẹbirin ti o wà lẹhin ọlọ; ati gbogbo akọ́bi ẹran.

6 Ẹkún nla yio si wà ni gbogbo ilẹ Egipti, eyiti irú rẹ̀ kò sí rí, ti ki yio si sí irú rẹ̀ mọ́.

7 Ṣugbọn si ọkan ninu awọn ọmọ Israeli li ajá ki yio yọ ahọn rẹ̀, si enia tabi si ẹran; ki ẹnyin ki o le mọ̀ bi OLUWA ti fi ìyatọ sãrin awọn ara Egipti ati Israeli.

8 Gbogbo awọn iranṣẹ rẹ wọnyi ni yio si sọkalẹ tọ̀ mi wá, ti nwọn o si fori wọn balẹ fun mi pe, Iwọ jade lọ ati gbogbo awọn enia ẹhin rẹ: lẹhin ìgba na li emi o to jade. O si jade kuro niwaju Farao ni ibinu nla.

9 OLUWA si wi fun Mose pe, Farao ki yio gbọ́ tirẹ; ki a le sọ iṣẹ-iyanu mi di pupọ̀ ni ilẹ Egipti.

10 Mose ati Aaroni si ṣe gbogbo iṣẹ-iyanu wọnyi niwaju Farao: OLUWA si mu àiya Farao le, bẽni kò si fẹ́ jẹ ki awọn ọmọ Israeli ki o jade lọ kuro ni ilẹ rẹ̀.

## ORI 12.

OLUWA si sọ fun Mose ati Aaroni ni ilẹ Egipti pe,

2 Oṣù yi ni yio ṣe akọ́kà oṣù fun nyin: on ni yio ṣe ekini oṣù ọdún fun nyin.

3 Ẹ sọ fun gbogbo ijọ awọn enia Israeli

Digitized by Google

pe, Ni ijọ́ kẹwa oṣù yi ni ki olukuluku wọn ki o mú ọdọ-agutan sọdọ, gẹgẹ bi ile baba wọn, ọdọ agutan kan fun ile kan:

4 Bi awọn ara ile na ba si kere jù ìwọn ọdọ-agutan na lọ, ki on ati aladugbo rẹ̀ ti o sunmọ-eti ile rẹ̀, ki o mú gẹgẹ bi iye awọn ọkàn na, olukuluku ni ìwọn ijẹ rẹ̀ ni ki ẹ ṣiro ọdọ-agutan na.

5 Ailabùkun ni ki ọdọ-agutan nyin ki o jẹ́, akọ ọlọdún kan: ẹnyin o mú u ninu agutan, tabi ninu ewurẹ:

6 Ẹnyin o si fi i pamọ́ titi o fi di ijọ́ kẹrinla oṣù na: gbogbo agbajọ ijọ Israeli ni yio pa a li aṣalẹ.

7 Nwọn o si mú ninu ẹ̀jẹ na, nwọn o si fi tọ́ ara opó ìha mejeji, ati sara atẹrigba ile wọnni, ninu eyiti nwọn o jẹ ẹ.

8 Nwọn o si jẹ ẹran na ti a fi iná sun li oru na, ati àkara alaiwu; ewebẹ kikorò ni nwọn o fi jẹ ẹ.

9 Ẹ máṣe jẹ ninu rẹ̀ ni tutù, tabi ti a fi omi bọ̀, bikoṣepe sisun ninu iná; ati ori rẹ̀, ati itan rẹ̀, ati akopọ̀ inu rẹ̀ pẹlu.

10 Ẹ kò si gbọdọ jẹ ki nkan ki o kù silẹ ninu rẹ̀ dé ojumọ́; eyiti o ba si kù di ijọ́ keji on ni ki ẹnyin ki o daná sun.

11 Bayi li ẹnyin o si jẹ ẹ; ti ẹnyin ti àmure didì li ẹgbẹ nyin, bàta nyin li ẹsẹ̀ nyin, ati ọpá nyin li ọwọ́ nyin, ẹnyin o si yara jẹ ẹ: irekọja OLUWA ni.

12 Nitoriti emi o là ilẹ Egipti já li oru na, emi o si kọlù gbogbo awọn akọ́bi ni ilẹ Egipti, ti enia ati ti ẹran; ati lara gbogbo oriṣa Egipti li emi o ṣe idajọ: emi li OLUWA.

13 Ẹ̀jẹ na ni yio si ṣe àmi fun nyin lara ile ti ẹnyin gbé wà: nigbati emi ba ri ẹ̀jẹ na, emi o ré nyin kọja, iyọnu na ki yio wà sori nyin lati run nyin nigbati mo ba kọlù ilẹ Egipti.

14 Ọjọ́ oni ni yio si ma ṣe ọjọ́ iranti fun nyin, ẹnyin o si ma ṣe e li ajọ fun OLUWA ni iran-iran nyin, ẹ o si ma ṣe e li ajọ nipa ìlana lailai.

15 Ijọ́ meje li ẹ o fi ma jẹ àkara alaiwu; li ọjọ́ kini gan li ẹ o palẹ iwukàra mọ́ kuro ni ile nyin; nitori ẹniti o ba jẹ àkara wiwu lati ọjọ́ kini lọ titi o fi di ọjọ́ keje, ọkàn na li a o ke kuro ninu Israeli.

16 Ati li ọjọ́ kini ki apejọ mimọ́ ki o wà, ati li ọjọ́ keje apejọ mimọ́ yio wà fun nyin; a ki yio ṣe iṣẹkiṣẹ ninu wọn, bikoṣe eyiti olukuluku yio jẹ, kìki eyinì li a le ṣe ninu nyin.

17 Ẹ o si kiyesi ajọ aiwukàra; nitori li ọjọ́ na gan ni mo mú ogun nyin jade kuro ni ilẹ Egipti; nitorina ni ki ẹ ma kiyesi ọjọ́ na ni iran-iran nyin nipa ìlana lailai.

18 Li oṣù kini li ọjọ kẹrinla oṣù na li aṣalẹ li ẹ o jẹ àkara alaiwu, titi yio fi di ọjọ́ kọkanlelogun oṣù na li aṣalẹ.

19 Ni ọjọ́ meje ni ki a máṣe ri iwukàra ninu ile nyin: nitori ẹniti o ba jẹ eyiti a wu, ọkàn na li a o ke kuro ninu ijọ Israeli, iba ṣe alejò, tabi ẹniti a bí ni ilẹ na.

20 Ẹ kò gbọdọ jẹ ohunkohun ti a wu; ninu ibugbé nyin gbogbo li ẹnyin o jẹ àkara alaiwu.

21 Nigbana ni Mose pè gbogbo awọn àgba Israeli, o si wi fun wọn pe, Ẹ jade lọ imú ọdọ-agutan fun ara nyin, gẹgẹ bi idile nyin, ki ẹ si pa irekọja na.

22 Ẹnyin o si mú ìdi ewe-hissopu, ẹ o si fi bọ̀ ẹ̀jẹ ti o wà ninu awokoto, ẹ o si fi ẹ̀jẹ na ti o wà ninu awokoto kùn ara atẹrigba, ati opó ìha mejeji; ẹnikẹni ninu nyin kò si gbọdọ jade lati ẹnu-ọna ile rẹ̀ titi yio fi di owurọ̀.

23 Nitoriti OLUWA yio kọja lati kọlù awọn ara Egipti; nigbati o ba si ri ẹ̀jẹ lara atẹrigba, ati lara opó ìha mejeji, OLUWA yio si rekọja ẹnu-ọna na, ki yio jẹ ki apanirun ki o wọle nyin wá lati kọlù nyin.

24 Ẹ o si ma kiyesi nkan yi nipa ìlana fun ọ, ati fun awọn ọmọ rẹ lailai.

25 O si ṣe, nigbati ẹ ba dé ilẹ na ti OLUWA yio fi fun nyin, gẹgẹ bi o ti wi, bẽli ẹ o si ma kiyesi ìsin yi.

26 Yio si ṣe nigbati awọn ọmọ nyin ba bi nyin pe, Eredi ìsin yi?

27 Ki ẹ wipe, Ẹbọ irekọja OLUWA ni, ẹniti o rekọja ile awọn ọmọ Israeli ni Egipti, nigbati o kọlù awọn ara Egipti, ti o si dá ile wa si. Awọn enia si tẹriba nwọn si sìn.

28 Awọn ọmọ Israeli si lọ, nwọn si ṣe bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose ati Aaroni, bẽni nwọn ṣe.

29 O si ṣe lãrin ọganjọ́ li OLUWA pa gbogbo awọn akọ́bi ni ilẹ Egipti, lati akọ́bi Farao lọ ti o joko lori itẹ́ rẹ̀ titi o fi dé akọ́bi ẹrú ti o wà ni túbu; ati gbogbo akọ́bi ẹran-ọsin.

30 Farao si dide li oru, on ati gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀, ati awọn ara Egipti; igbe nla si ta ni Egipti; nitoriti kò sí ile kan ti enia kan kò kú.

31 O si pè Mose on Aaroni li oru, o si wipe, Ẹ dide, ki ẹ jade lọ kuro lãrin awọn enia mi, ati ẹnyin ati awọn ọmọ Israeli; ki ẹ si lọ sìn OLUWA, bi ẹ ti wi.

32 Ẹ si mú agbo nyin ati ọwọ́-ẹran nyin,

Digitized by Google

bi ẹ ti wi, ki ẹ si ma lọ; ki ẹ si sure fun
mi pẹlu.
33 Awọn ara Egipti si nrọ̀ awọn enia na,
ki nwọn ki o le rán wọn jade lọ kuro ni ilẹ
na kánkan; nitoriti nwọn wipe, Gbogbo
wa di okú.
34 Awọn enia na si mú iyẹfun pipò wọn
ki nwọn ki o to fi iwukàra si i, a si dì ọpọ́n
ìpo-iyẹfun wọn sinu aṣọ wọn lé ejika wọn.
35 Awọn ọmọ Israeli si ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ
Mose; nwọn si bère ohun-èlo fadaka, ati
ohun-èlo wurà, ati aṣọ lọwọ awọn ara
Egipti.
36 OLUWA si fun awọn enia na li ojurere
li oju awọn ara Egipti, bẹ̃ni nwọn si fun
wọn li ohun ti nwọn bère. Nwọn si kó ẹrù
awọn ara Egipti.
37 Awọn ọmọ Israeli si rìn lati Ramesesi
lọ si Sukkotu, nwọn to ìwọn ọgbọ̀n ọkẹ
ẹlẹsẹ̀ ọkọnrin, li àika ọmọde.
38 Ati ọ̀pọ enia ti o dàpọ mọ́ wọn bá wọn
goke lọ pẹlu; ati agbo, ati ọwọ́-ẹran, ani
ọ̀pọlọpọ ẹran.
39 Nwọn si yan àkara iyẹfun pipò alaiwu
ti nwọn mú jade ti Egipti wá, nwọn kò sa
fi iwukàra si i; nitoriti a tì wọn jade kuro
ni Egipti, nwọn kò si le duro, bẹ̃ni nwọn
kò pèse ohun jijẹ kan fun ara wọn.
40 Njẹ ìgba atipo awọn ọmọ Israeli ti
nwọn ṣe ni ilẹ Egipti, o jẹ́ irinwo ọdún o le
ọgbọ̀n.
41 O si ṣe li opin irinwo ọdún o le ọgbọ̀n,
ani li ọjọ́ na gan, li o si ṣe ti gbogbo ogun
OLUWA jade kuro ni ilẹ Egipti.
42 Oru ti a ikiyesi ni gidigidi si OLUWA,
ni mimú wọn jade kuro ni ilẹ Egipti: eyi
li oru ti a ikiyesi si OLUWA, li ati irandiran
gbogbo awọn ọmọ Israeli.
43 OLUWA si wi fun Mose ati Aaroni pe,
Eyi ni ìlana irekọja: alejokalejò ki yio jẹ
ninu rẹ̀:
44 Ṣugbọn iranṣẹ ẹnikẹni ti a fi owo rà,
nigbati iwọ ba kọ ọ nilà, nigbana ni ki o jẹ
ninu rẹ̀.
45 Alejò ati alagbaṣe ki yio jẹ ninu rẹ̀.
46 Ni ile kan li a o jẹ ẹ; iwọ kò gbọdọ
mú ninu ẹran rẹ̀ jade sode kuro ninu ile na;
bẹ̃li ẹnyin kò gbọdọ ṣẹ́ ọkan ninu egungun
rẹ̀.
47 Gbogbo ijọ Israeli ni yio ṣe e.
48 Nigbati alejò kan ba nṣe atipo lọdọ
rẹ, ti o si nṣe ajọ irekọja si OLUWA, ki a kọ
gbogbo ọkọnrin rẹ̀ nilà, nigbana ni ki ẹ jẹ
ki o sunmọtosi, ki o si ṣe e; on o si dabi
ẹniti a bí ni ilẹ na: nitoriti kò sí ẹni
alaikọlà ti yio jẹ ninu rẹ̀.
49 Ofin kan ni fun ibilẹ ati fun alejò ti
o ṣe atipo ninu nyin.
50 Bẹ̃ni gbogbo awọn ọmọ Israeli ṣe; bi
OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose ati Aaroni, bẹ̃ni
nwọn ṣe.
51 O si ṣe li ọjọ́ na gan, OLUWA mú
awọn ọmọ Israeli jade kuro ni ilẹ Egipti,
gẹgẹ bi ogun wọn.

## ORI 13.

OLUWA si wi fun Mose pe,
2 Yà gbogbo awọn akọ́bi sọ̀tọ fun mi,
gbogbo eyiti iṣe akọ́bi ninu awọn ọmọ
Israeli, ati ti enia, ati ti ẹran: ti emi ni iṣe.
3 Mose si wi fun awọn enia na pe, Ẹ
ranti ọjọ́ oni, ninu eyiti ẹnyin jade kuro ni
Egipti, kuro li oko-ẹrú; nitori ọwọ́ agbara
li OLUWA fi mú nyin jade kuro nihin: a ki
yio si jẹ àkara wiwu.
4 Li ọjọ́ oni li ẹnyin jade li oṣù Abibu.
5 Yio si ṣe nigbati OLUWA yio mú ọ dé
ilẹ awọn ara Kenaani, ati ti awọn enia
Hitti, ati ti awọn ara Amori, ati awọn Hifi,
ati awọn Jebusi, ti o ti bura fun awọn baba
rẹ lati fi fun ọ, ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun
oyin, on ni iwọ o ma sìn ìsin yi li oṣù yi.
6 Ijọ́ meje ni iwọ o fi jẹ àkara alaiwu, li
ọjọ́ keje li ajọ yio wà fun OLUWA.
7 Ọjọ́ meje li a o fi jẹ àkara alaiwu; ki a
má si ṣe ri àkara wiwu lọdọ rẹ, bẹ̃ni ki a
má si ṣe ri iwukàra lọdọ rẹ ni gbogbo ẹkùn
rẹ.
8 Iwọ o si sọ fun ọmọ rẹ li ọjọ́ na pe, A
nṣe eyi nitori eyiti OLUWA ṣe fun mi
nigbati mo jade kuro ni Egipti.
9 Yio si ma ṣe àmi fun ọ li ọwọ́ rẹ, ati
fun àmi iranti li agbedemeji oju rẹ, ki ofin
OLUWA ki o le wà li ẹnu rẹ: nitori ọwọ́
agbara li OLUWA fi mú ọ jade kuro ni Egipti.
10 Nitorina ni ki iwọ ki o ma kiyesi
ilana yi li akokò rẹ̀ li ọdọdún.
11 Yio si ṣe nigbati OLUWA ba mú ọ dé
ilẹ awọn ara Kenaani, bi o ti bura fun ọ,
ati fun awọn baba rẹ, ti yio si fi fun ọ.
12 Ni iwọ o si yà gbogbo akọ́bi sọ̀tọ fun
OLUWA, ati gbogbo akọ́bi ẹran ti iwọ ní;
ti OLUWA li awọn akọ.
13 Ati gbogbo akọ́bi kẹtẹkẹtẹ ni ki iwọ
ki o fi ọdọ-agutan rapada; bi iwọ kò ba rà
a pada, njẹ ki iwọ ki o ṣẹ ẹ li ọrùn: ati
gbogbo akọ́bi enia ninu awọn ọmọ okọnrin
rẹ ni iwọ o rapada.
14 Yio si ṣe nigbati ọmọ rẹ yio bère lọwọ
rẹ lẹhin-ọla pe, Kili eyi? ki iwọ ki o wi
fun u pe, Ọwọ́ agbara li OLUWA fi mú wa
jade kuro ni ilẹ Egipti, kuro li oko-ẹrú:

Digitized by Google

15 O si ṣe, nigbati Farao kọ̀ lati jẹ ki a
lọ, on li OLUWA pa gbogbo akọ́bi ni ilẹ
Egipti, ati akọ́bi enia, ati akọ́bi ẹran;
nitorina ni mo ṣe fi gbogbo akọ́bi ti iṣe
akọ rubọ si OLUWA; ṣugbọn gbogbo awọn
akọ́bi ọmọ okọnrin mi ni mo rapada.
16 Yio si ma ṣe àmi li ọwọ́ rẹ, ati ọjá-
igbaju lagbedemeji oju rẹ: nitori ọwọ́
agbara li OLUWA fi mú wa jade kuro ni
Egipti.
17 O si ṣe, nigbati Farao jẹ ki awọn enia
na ki o lọ tán, Ọlọrun kò si mú wọn tọ̀ ọ̀na
ilẹ awọn ara Filistia, eyi li o sa yá; nitoriti
Ọlọrun wipe, Ki awọn enia má ba yi ọkàn
pada nigbati nwọn ba ri ogun, ki nwọn si
pada lọ si Egipti.
18 Ṣugbọn Ọlọrun mu wọn yi lọ li ọ̀na
ijù Okun Pupa: awọn ọmọ Israeli jade lọ
kuro ni ilẹ Egipti ni ihamọra.
19 Mose si gbé egungun Josefu lọ pẹlu
rẹ̀; nitori ibura lile li o mu awọn ọmọ
Israeli bu pe, Lõtọ li Ọlọrun yio bẹ̀ nyin
wò; ki ẹnyin ki o si rù egungun mi lọ pẹlu
nyin kuro nihin.
20 Nwọn si mu ọ̀na-àjo wọn pọ̀n lati
Sukkoti lọ, nwọn si dó si Etamu leti ijù.
21 OLUWA si nlọ niwaju wọn, ninu
ọwọ̀n awọsanma li ọsán, lati ma ṣe amọ-
na fun wọn; ati li oru li ọwọ̀n iná lati ma
fi imọlẹ fun wọn; lati ma rìn li ọsán ati li
oru.
22 Ọwọ̀n awọsanma na kò kuro li ọsán,
tabi ọwọ̀n iná li oru, niwaju awọn enia na.

## ORI 14.

OLUWA si wi fun Mose pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, ki
nwọn ki o darí, ki nwọn ki o si dó si iwaju
Pi-hahirotu, li agbedemeji Migdolu on o-
kun, niwaju Baal-sefoni: lọkankan rẹ̀ li
ẹba okun ni ki ẹnyin ki o dó si.
3 Nitoriti Farao yio wi niti awọn ọmọ
Israeli pe, Nwọn há ni ilẹ na, ijù na sé
wọn mọ́.
4 Emi o si mu àiya Farao le, ti yio fi
lepa wọn; a o si yìn mi logo lori Farao, ati
lori ogun rẹ̀ gbogbo; ki awọn ara Egipti
ki o le mọ̀ pe, emi li OLUWA. Nwọn si ṣe
bẽ.
5 A si wi fun ọba Egipti pe, awọn enia
na sá: àiya Farao ati awọn iranṣẹ rẹ̀ si
yi si awọn enia na, nwọn si wipe, Ẽṣe ti
awa fi ṣe eyi, ti awa fi jẹ ki Israeli ki o lọ
kuro ninu ìsin wa?
6 O si dì kẹkẹ́ rẹ̀, o si mú awọn enia rẹ̀
pẹlu rẹ̀.
7 O si mú ẹgbẹta ãyo kẹkẹ́, ati gbogbo
kẹkẹ́ Egipti, ati olori si olukuluku wọn.
8 OLUWA si mu àiya Farao ọba Egipti
le, o si lepa awọn ọmọ Israeli: ọwọ́ giga li
awọn ọmọ Israeli si fi jade lọ.
9 Ṣugbọn awọn ara Egipti lepa wọn,
gbogbo ẹṣin ati kẹkẹ́ Farao, ati awọn ẹlẹṣin
rẹ̀, ati awọn ogun rẹ̀, o si lé wọn bá, nwọn
duro li ẹba okun ni ìha Pi-hahirotu niwaju
Baal-sefoni.
10 Nigbati Farao si nsunmọtosi, awọn
ọmọ Israeli gbé oju soke, si kiyesi i, awọn
ara Egipti mbọ̀ lẹhin wọn; ẹ̀ru si bà wọn
gidigidi: awọn ọmọ Israeli si kigbe pè
OLUWA.
11 Nwọn si wi fun Mose pe, Nitoriti isà
kò sí ni Egipti, ki iwọ ṣe mú wa wá lati
kú ni ijù? ẽṣe ti iwọ fi ṣe wa bẽ, lati mú
wa jade ti Egipti wá?
12 Ọrọ yi ki awa ti sọ fun ọ ni Egipti
pe, Jọwọ wa jẹ ki awa ki o ma sìn awọn
ara Egipti? O sá san fun wa lati ma sìn
awọn ara Egipti, jù ki awa kú li aginjù lọ.
13 Mose si wi fun awọn enia na pe, Ẹ
má bẹ̀ru, ẹ duro jẹ, ki ẹ si ri ìgbala OLUWA,
ti yio fihàn nyin li oni: nitori awọn ara
Egipti ti ẹnyin ri li oni yi, ẹnyin ki yio si
tun ri wọn mọ́ lailai.
14 Nitoriti OLUWA yio jà fun nyin, ki
ẹnyin ki o si pa ẹnu nyin mọ́.
15 OLUWA si wi fun Mose pe, Ẽṣe ti iwọ
fi nkepè mi? sọ fun awọn ọmọ Israeli ki
nwọn ki o tẹ̀ siwaju:
16 Ṣugbọn iwọ gbe ọpá rẹ soke, ki iwọ
ki o si nà ọwọ́ rẹ si oju okun ki o si yà a
meji: awọn ọmọ Israeli yio si là ãrin okun
na kọja ni iyangbẹ ilẹ.
17 Atiemi, kiyesi i, emi o mu àiya awọn
ara Egipti le, nwọn o si tẹle wọn: a o si
yìn mi logo lori Farao, ati lori gbogbo
ogun rẹ̀, ati lori awọn kẹkẹ́ rẹ̀, ati lori
awọn ẹlẹṣin rẹ̀.
18 Awọn ara Egipti yio si mọ̀ pe, emi li
OLUWA, nigbati mo ba gbà ogo lori Farao,
lori awọn kẹkẹ́ rẹ̀, ati lori awọn ẹlẹṣin rẹ̀.
19 Angeli Ọlọrun na ti o ṣaju ogun Isra-
eli, o si ṣí lọ sẹhin wọn; ọwọ̀n awọsanma
si ṣí kuro niwaju wọn, o si duro lẹhin
wọn:
20 O si wá si agbedemeji ogun awọn ara
Egipti ati ogun Israeli; o si ṣe awọsanma
ati òkunkun fun awọn ti ọhùn, ṣugbọn o
ṣe imọlẹ li oru fun awọn ti ihin: bẽli eki-
ni kò sunmọ ekeji ni gbogbo oru na.
21 Mose si nà ọwọ́ rẹ̀ si oju okun; OLU-
WA si fi afẹfẹ lile ìla-õrùn mu okun bì sẹ-

Digitized by Google

hin ni gbogbo oru na, o si mu okun gbẹ:
omi na si pinya.
22 Awọn ọmọ Israeli si lọ sinu ãrin
okun ni ilẹ gbigbẹ: omi si ṣe odi si wọn li
ọwọ ọtún, ati ọwọ òsi.
23 Awọn ara Egipti si lepa wọn, nwọn
si wọ̀ ọ tọ̀ wọn lọ lãrin okun, ati gbogbo
ẹṣin Farao, ati kẹkẹ́ rẹ̀, ati awọn ẹlẹṣin rẹ̀.
24 O si ṣe, nigba iṣọ owurọ̀, OLUWA bojuwò
ogun ara Egipti lãrin ọwọ̀n iná, ati ti
awọsanma, o si pá ogun awọn ara Egipti
làiya.
25 O si yẹ̀ kẹkẹ́ wọn, nwọn si nwọ́ turu,
awọn ara Egipti si wipe, Ẹ jẹ ki a sá kuro
niwaju Israeli; nitoriti OLUWA mbá awọn
ara Egipti jà fun wọn.
26 OLUWA si wi fun Mose pe, Nà ọwọ́
rẹ si oju okun, ki omi ki o tun pada wá sori
awọn ara Egipti, sori kẹkẹ́ wọn, ati sori
ẹlẹṣin wọn.
27 Mose si nà ọwọ́ rẹ̀ si oju okun, okun
si pada bọ̀ si ipò rẹ̀ nigbati ilẹ mọ́; awọn
ara Egipti si sá lù u. OLUWA si bì awọn
ara Egipti ṣubu lãrin okun.
28 Omi si pada, o si bò kẹkẹ́, ati awọn
ẹlẹṣin, ati gbogbo ogun Farao ti o wọ̀ inu
okun tọ̀ wọn lẹhin lọ; ọkanṣoṣo kò kù ninu
wọn.
29 Ṣugbọn awọn ọmọ Israeli rìn ni iyangbẹ
ilẹ lãrin okun; omi si jẹ́ odi fun wọn
li ọwọ́ ọtún, ati li ọwọ́ òsi wọn.
30 Bayi li OLUWA gbà Israeli là li ọjọ́
na lọwọ awọn ara Egipti; Israeli si ri okú
awọn ara Egipti leti okun.
31 Israeli si ri iṣẹ nla ti OLUWA ṣe lara
awọn ara Egipti: awọn enia na si bẹru
OLUWA, nwọn si gbà OLUWA ati Mose iranṣẹ
rẹ̀ gbọ́.

## ORI 15.

NIGBANA ni Mose ati awọn ọmọ Israeli
kọ orin yi si OLUWA nwọn si wipe,
Emi o kọrin si OLUWA, nitoriti o pọ̀ li ogo:
ati ẹṣin ati ẹlẹṣin on li o bì ṣubu sinu okun.
2 OLUWA li agbara ati orin mi, on li o si
di ìgbala mi: eyi li Ọlọrun mi, emi o si fi
ìyin fun u; Ọlọrun baba mi, emi o gbé e
leke.
3 Ologun li OLUWA; OLUWA li orukọ rẹ̀.
4 Kẹkẹ́ Farao ati ogun rẹ̀ li o mu wọ̀ inu
okun: awọn ãyo olori ogun rẹ̀ li o si rì ninu
Okun Pupa.
5 Ibú bò wọn mọlẹ: nwọn rì si isalẹ bi
okuta.
6 OLUWA, ọwọ́ ọtún rẹ li ogo ninu agbara:
OLUWA, ọwọ́ ọtún rẹ fọ́ ọtá tútu.
7 Ati ni ọ̀pọlọpọ ọlá rẹ ni iwọ bì awọn ti
o dide si ọ ṣubu; iwọ rán ibinu rẹ, ti o run
wọn bi akemọlẹ idi koriko.
8 Ati nipa ẽmi imu rẹ, li omi si fi wọjọ
pọ̀, ìṣan omi dide duro gangan bi ogiri;
ibú si dìlu lãrin okun.
9 Ọtá wipe, Emi o lepa, emi o bá wọn,
emi o pín ikogun: a o tẹ́ ifẹkufẹ mi lọrùn
lara wọn; emi o fà idà mi yọ, ọwọ́ mi ni yio
pa wọn run.
10 Iwọ si mu afẹfẹ rẹ fẹ́, okun bò wọn
mọlẹ: nwọn rì bi ojé ninu omi nla.
11 Tali o dabi iwọ, OLUWA, ninu awọn
alagbara? tali o dabi iwọ, ologo ni mimọ́,
ẹlẹru ni iyìn, ti nṣe ohun iyanu?
12 Iwọ nà ọwọ́ ọtún rẹ, ilẹ gbe wọn mì.
13 Ninu ãnu rẹ ni iwọ fi ṣe amọ̀na awọn
enia na ti iwọ ti rapada: iwọ si nfi agbara
rẹ tọ́ wọn lọ si ibujoko mimọ́ rẹ.
14 Awọn enia gbọ́, nwọn wariri; ikãnu
si mú awọn olugbe Palestina.
15 Nigbana li ẹnu yà awọn balẹ Edomu;
iwarìri si mú awọn alagbara Moabu: gbogbo
awọn olugbe Kenaani yọ́ dànu.
16 Ibẹru-bojo mú wọn; nipa titobi apa
rẹ nwọn duro jẹ bi okuta; titi awọn enia
rẹ fi rekọja, OLUWA, titi awọn enia rẹ ti
iwọ ti rà fi rekọja.
17 Iwọ o mú wọn wọle, iwọ o si gbìn
wọn sinu oke ilẹ-iní rẹ, OLUWA, ni ibi ti
iwọ ti ṣe fun ara rẹ lati ma gbé, OLUWA;
ni ibi mimọ́ na, ti ọwọ́ rẹ ti gbekalẹ.
18 OLUWA yio jọba lai ati lailai.
19 Nitori ẹṣin Farao wọ̀ inu okun lọ, pelu
kẹkẹ́ rẹ̀ ati awọn ẹlẹṣin rẹ̀, OLUWA si
tun mú omi okun pada si wọn lori; ṣugbọn
awọn ọmọ Israeli rìn ni ilẹ gbigbẹ
lãrin okun.
20 Ati Miriamu wolĩ obirin, arabirin
Aaroni, o mú ìlu li ọwọ́ rẹ̀: gbogbo awọn
obirin si jade tẹle e ti awọn ti ìlu ati ijó.
21 Miriamu si da wọn li ohùn pe, Ẹ kọrin
si OLUWA nitoriti o pọ̀ li ogo; ẹṣin ati
ẹlẹṣin on li o bì ṣubu sinu okun.
22 Bẹ̃ni Mose mú Israeli jade lati Okun
Pupa wá, nwọn si jade lọ si ijù Ṣuri; nwọn
si lọ ni ìrin ijọ́ mẹta ni ijù na, nwọn kò si
ri omi.
23 Nigbati nwọn dé Mara, nwọn ko le
mu ninu omi Mara, nitoriti o koro; nitorina
li a ṣe sọ orukọ rẹ̀ ni Mara.
24 Awọn enia na si nkùn si Mose wipe,
Kili awa o mu?
25 O si kepè OLUWA; OLUWA si fi igi
kan hàn a, nigbati o si sọ ọ sinu omi na,
omi si di didùn. Nibẹ̀ li o si gbé ṣe ofin

Digitized by Google

ati ìlana fun wọn, nibẹ̀ li o si gbé dán wọn wò;

26 O si wipe, Bi iwọ o ba tẹtisilẹ gidigidi si ohùn OLUWA Ọlọrun rẹ, ti o ba si ṣe eyiti o tọ́ li oju rẹ̀, ti iwọ o ba si fetisi ofin rẹ̀, ti iwọ o ba si pa gbogbo aṣẹ rẹ̀ mọ́, emi ki yio si fi ọkan ninu àrun wọnni ti mo múwa sara awọn ara Egipti si ọ lara: nitori emi li OLUWA ti o mu ọ lara dá.

27 Nwọn si dé Elimu, nibiti kanga omi mejila gbé wà, ati ãdọrin ọpẹ: nwọn si dó si ìha omi wọnni nibẹ̀.

## ORI 16.

NWỌN si ṣí lati Elimu, gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli si dé ijù Sini, ti o wà li agbedemeji Elimu on Sinai, ni ijọ́ kẹdogun oṣù keji, lẹhin igbati nwọn jade kuro ni ilẹ Egipti.

2 Gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli si nkùn si Mose ati si Aaroni ni ijù na:

3 Awọn ọmọ Israeli si wi fun wọn pe, Awa iba ti ti ọwọ́ OLUWA kú ni Egipti, nigbati awa joko ti ìkoko ẹran, ti awa njẹ ajẹyo; ẹnyin sá mú wa jade wá si ijù yi, lati fi ebi pa gbogbo ijọ yi.

4 Nigbana li OLUWA sọ fun Mose pe, Kiyesi i, emi o rọ̀jo onjẹ fun nyin lati ọrun wá; awọn enia yio si ma jade lọ ikó ìwọn ti õjọ li ojojumọ́, ki emi ki o le dan wọn wò, bi nwọn o fẹ́ lati ma rìn nipa ofin mi, bi bẹ̃kọ.

5 Yio si ṣe, li ọjọ́ kẹfa, nwọn o si pèse eyiti nwọn múwa; yio si to ìwọn meji eyiti nwọn ima kó li ojojumọ́.

6 Mose ati Aaroni si wi fun gbogbo awọn ọmọ Israeli pe, Li aṣalẹ, li ẹnyin o si mọ̀ pe, OLUWA li o mú nyin jade lati Egipti wá:

7 Ati li owurọ̀ li ẹnyin o si ri ogo OLUWA; nitoriti o gbọ́ kikùn nyin si OLUWA: ta si li awa, ti ẹnyin nkùn si wa?

8 Mose si wi pe, Bayi ni yio rí nigbati OLUWA yio fun nyin li ẹran jẹ li aṣalẹ, ati onjẹ ajẹyo li owurọ̀; nitoriti OLUWA gbọ́ kikùn nyin ti ẹnyin kùn si i: ta si li awa? kikùn nyin ki iṣe si wa, bikoṣe si OLUWA.

9 Mose si sọ fun Aaroni pe, Sọ fun gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli pe, Ẹ sunmọ iwaju OLUWA, nitoriti o ti gbọ́ kikùn nyin.

10 O si ṣe, nigbati Aaroni nsọ fun gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli, nwọn si bojuwò ìha ijù, si kiyesi i, ogo OLUWA hàn li awọsanma na.

11 OLUWA si sọ fun Mose pe,

12 Emi ti gbọ́ kikùn awọn ọmọ Israeli: sọ fun wọn pe, Li aṣalẹ ẹnyin o jẹ ẹran, ati li owurọ̀ a o si fi onjẹ kún nyin; ẹnyin o si mọ̀ pe, emi li OLUWA Ọlọrun nyin.

13 O si ṣe li aṣalẹ ni aparò fò dé, nwọn si bò ibudó mọlẹ; ati li owurọ̀ ìri si sẹ̀ yi gbogbo ibudó na ká.

14 Nigbati ìri ti o sẹ̀ bolẹ si fà soke, si kiyesi i, lori ilẹ ijù na, ohun ribiribi, o kere bi ìri didì li ori ilẹ.

15 Nigbati awọn ọmọ Israeli si ri i, nwọn wi fun ara wọn pe, Kili eyi? nitoriti nwọn kò mọ̀ ohun na. Mose si wi fun wọn pe, Eyi li onjẹ ti OLUWA fi fun nyin lati jẹ.

16 Eyi li ohun ti OLUWA ti palaṣẹ, ki olukuluku ki o ma kó bí ìwọn ijẹ rẹ̀; òṣuwọn omeri kan fun ẹni kọkan, gẹgẹ bi iye awọn enia nyin, ki olukuluku nyin mú fun awọn ti o wà ninu agọ́ rẹ̀.

17 Awọn ọmọ Israeli si ṣe bẹ̃, nwọn si kó, ẹlomiran pupọ̀jù, ẹlomiran li aito.

18 Nigbati nwọn si fi òṣuwọn omeri wọ̀n ọ, ẹniti o kó pupọ̀ kò ní nkan lé, ẹniti o si kó kere jù, kò ṣe alaito; nwọn si kó olukuluku bi ijẹ tirẹ̀.

19 Mose si wi fun wọn pe, Ki ẹnikan ki o má kùsilẹ ninu rẹ̀ titi di owurọ̀.

20 Ṣugbọn nwọn kò gbọ́ ti Mose; bẹ̃li ẹlomiran si kùsilẹ ninu rẹ̀ titi di owurọ̀, o o si di idin, o si rùn; Mose si binu si wọn.

21 Nwọn si nkó o li orowurọ̀, olukuluku bi ijẹ tirẹ̀; nigbati õrùn si mu, o yọ́.

22 O si ṣe ni ijọ́ kẹfa, nwọn kó ìwọn onjẹ ẹrinmeji, omeri meji fun ẹni kọkan: gbogbo awọn olori ijọ na si wá nwọn sọ fun Mose.

23 O si wi fun wọn pe, Eyi na li OLUWA ti wi pe, Ọla li ọjọ́ isimi, isimi mimọ́ fun OLUWA; ẹ yan eyiti ẹnyin ni iyan, ki ẹ si bọ̀ eyiti ẹnyin ni ibọ̀; eyiti o si kù, ẹ fi i silẹ lati pa a mọ́ dé owurọ̀.

24 Nwọn si fi i silẹ titi di owurọ̀, bi Mose ti paṣẹ fun wọn; kò si rùn, bẹ̃ni kò sí idin ninu rẹ̀.

25 Mose si wi pe, Ẹ jẹ eyinì li oni; nitori oni li ọjọ́ isimi fun OLUWA: li oni ẹnyin ki yio ri i ninu igbẹ́.

26 Li ọjọ́ mẹfa li ẹ o ma kó o; ṣugbon li ọjọ́ keje li ọjọ́ isimi, ninu rẹ̀ ni ki yio sí nkan.

27 O si ṣe li ọjọ́ keje awọn kan ninu awọn enia jade lọ ikó, nwọn kò si ri nkan.

28 OLUWA si wi fun Mose pe, Ẹ o ti kọ̀ lati pa aṣẹ mi ati ofin mi mọ́ pẹ to?

29 Wò o, OLUWA sa ti fi ọjọ́ isimi fun nyin, nitorina li o ṣe fi onjẹ ijọ́ meji fun nyin li ọjọ́ kẹfa; ki olukuluku ki o joko ni

Digitized by Google

ipò rẹ̀, ki ẹnikẹni ki o máṣe jade kuro ni
ipò rẹ̀ li ọjọ́ keje.
30 Bẹ̃li awọn enia na simi li ọjọ́ keje.
31 Awọn ara ile Israeli si pè orukọ rẹ̀ ni
Manna ; o si dabi irugbìn korianderi, fun-
fun ; adùn rẹ̀ si dabi àkara fẹlẹfẹlẹ ti a fi
oyin ṣe.
32 Mose si wipe, Eyi li ohun ti OLUWA
palaṣẹ, Ẹ kún òṣuwọn omeri kan ninu rẹ̀
lati pamọ́ fun irandiran nyin ; ki nwọn ki
o le ma ri onjẹ ti mo fi bọ́ nyin ni ijù, ni-
gbati mo mú nyin jade kuro ni ilẹ Egipti.
33 Mose si wi fun Aaroni pe, Mú ìkoko
kan, ki o si fi òṣuwọn omeri kan ti o kún
fun manna sinu rẹ̀, ki o si gbé e kalẹ niwa-
ju OLUWA, lati pa a mọ́ fun irandiran nyin.
34 Bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose, bẹ̃li
Aaroni gbé e kalẹ niwaju ibi Ẹrí lati pa a
mọ́.
35 Awọn ọmọ Israeli si jẹ manna li ogoji
ọdún, titi nwọn fi dé ilẹ ti a tẹ̀dó ; nwọn
jẹ manna titi nwọn fi dé àgbegbe ilẹ Kena-
ani.
36 Njẹ òṣuwọn omeri kan ni idamẹwa
efa.

## ORI 17.

GBOGBO ijọ awọn ọmọ Israeli si rìn lati
ijù Sini lọ, ni ìrin wọn, gẹgẹ bi ofin
OLUWA, nwọn si dó ni Refidimu : omi kò
si sí fun awọn enia na lati mu.
2 Nitorina li awọn enia na ṣe mbá Mose
sọ̀, nwọn si wipe, Fun wa li omi ki a mu.
Mose si wi fun wọn pe, Èṣe ti ẹnyin fi mbà
mi sọ̀ ? ẽṣe ti ẹnyin fi ndán OLUWA wò ?
3 Ongbẹ omi si ngbẹ awọn enia na nìbẹ̀ ;
awọn enia na si nkùn si Mose, nwọn si wipe,
Ẽtiri ti iwọ fi mú wa goke lati Egipti wá,
lati fi ongbẹ pa wa ati awọn ọmọ wa, ati
ẹran wa ?
4 Mose si kepè OLUWA, wipe, Kili emi o
ṣe fun awọn enia yi ? nwọn fẹrẹ̀ sọ mi li
okuta.
5 OLUWA si wi fun Mose pe, Kọja lọ
siwaju awọn enia na, ki o si mú ninu awọn
àgbagba Israeli pẹlu rẹ, ki o si mú ọpá rẹ,
ti o fi lù odò nì li ọwọ́ rẹ, ki o si ma lọ.
6 Kiyesi i, emi o duro niwaju rẹ nibẹ̀ lori
okuta ni Horebu ; iwọ o si lù okuta na, omi
yio si jade ninu rẹ̀, ki awọn enia ki o le
mu. Mose si ṣe bẹ̃ li oju awọn àgbagba
Israeli.
7 O si sọ orukọ ibẹ̀ ni Massa, ati Meriba,
nitori asọ̀ awọn ọmọ Israeli, ati nitoriti
nwọn dan OLUWA wò pe, OLUWA ha mbẹ
lãrin wa, tabi kò sí ?
8 Nigbana li Amaleki wá, o si bá Israeli
jà ni Refidimu.
9 Mose si wi fun Joṣua pe, Yàn enia fun
wa, ki o si jade lọ ibá Amaleki jà : li ọla li
emi o duro lori oke ti emi ti ọpá Ọlọrun li
ọwọ́ mi.
10 Joṣua si ṣe bi Mose ti wi fun u, o si bá
Amaleki jà : ati Mose, Aaroni, on Huri lọ
sori oke na.
11 O si ṣe, nigbati Mose ba gbé ọwọ́ rẹ̀
soke, Israeli a bori : nigbati o ba si rẹ̀ ọwọ́
rẹ̀ silẹ, Amaleki a bori.
12 Ṣugbọn ọwọ́ kún Mose ; nwọn si mú
okuta kan, nwọn si fi si abẹ rẹ̀, o si joko lé
e ; Aaroni ati Huri si mu u li ọwọ́ ró, ọkan
li apa kini, ekeji li apa keji ; ọwọ́ rẹ̀ si duro
gan titi o fi di ìwọ-õrùn.
13 Joṣua si fi oju idà ṣẹgun Amaleki ati
awọn enia rẹ̀ tútu.
14 OLUWA si wi fun Mose pe, Kọ eyi
sinu iwe fun iranti, ki o si kà a li eti Joṣua ;
nitoriti emi o pa iranti Amaleki run pata-
pata kuro labẹ ọrun.
15 Mose si tẹ́ pẹpẹ kan, o si sọ orukọ rẹ̀
ni JEHOFA-nissi :
16 O si wipe, OLUWA ti bura : OLUWA
yio bá Amaleki jà lati irandiran.

## ORI 18.

NIGBATI Jetro, alufa Midiani, ana Mose,
gbọ́ ohun gbogbo ti Ọlọrun ti ṣe fun
Mose, ati fun Israeli awọn enia rẹ̀, ati pe,
OLUWA mú Israeli lati Egipti jade wá ;
2 Nigbana ni Jetro, ana Mose, mú
Sippora aya Mose wá, lẹhin ti o ti rán a
pada.
3 Ati awọn ọmọ rẹ̀ mejeji : ti orukọ
ọkan njẹ Gerṣomu ; nitoriti o wipe, Emi
ṣe alejò ni ilẹ ajeji.
4 Ati orukọ ekeji ni Elieseri ; nitoriti o
wipe, Ọlọrun baba mi li alatilẹhin mi, o si
gbà mi lọwọ idà Farao :
5 Ati Jetro, ana Mose, o tọ̀ Mose wá ti
on ti awọn ọmọ rẹ̀, ati aya rẹ̀ si ijù, nibiti
o gbé dó si lẹba oke Ọlọrun.
6 O si wi fun Mose pe, Emi Jetro ana rẹ li
o tọ̀ ọ wá, pẹlu aya rẹ, ati awọn ọmọ rẹ
mejeji pẹlu rẹ̀.
7 Mose si jade lọ ipade ana rẹ̀, o si
tẹriba, o si fi ẹnu kò o li ẹnu, nwọn si
bére alafia ara wọn ; nwọn si wọ̀ inu agọ́.
8 Mose si sọ ohun gbogbo ti OLUWA ti
ṣe si Farao, ati si awọn ara Egipti nitori
Israeli fun ana rẹ̀, ati gbogbo ipọnju ti o
bá wọn li ọ̀na, ati bi OLUWA ti gbà wọn.
9 Jetro si yọ̀ nitori gbogbo ore ti OLUWA



Digitized by Google

ti ṣe fun Israeli, ẹniti o ti gbà la lọwọ awọn ara Egipti.
10 Jetro si wipe, Olubukún li Oluwa, ẹniti o gbà nyin là lọwọ awọn ara Egipti, ati lọwọ Farao, ẹniti o gbà awọn enia là lọwọ awọn ara Egipti.
11 Mo mọ̀ nisisiyi pe Oluwa tobi jù gbogbo oriṣa lọ: nitõtọ, ninu ọ̀ran ti nwọn ti ṣefẹ́fe si wọn.
12 Jetro, ana Mose, si mu ẹbọ sisun, ati ẹbọ wá fun Ọlọrun: Aaroni si wá, ati gbogbo awọn àgba Israeli, lati bá ana Mose jẹun niwaju Ọlọrun.
13 O si ṣe ni ijọ́ keji ni Mose joko lati ma ṣe idajọ awọn enia: awọn enia si duro tì Mose lati owurọ̀ titi o fi di aṣalẹ.
14 Nigbati ana Mose si ri gbogbo eyiti on nṣe fun awọn enia, o ni, Kili eyiti iwọ nṣe fun awọn enia yi? ẽṣe ti iwọ nikan fi dá joko, ti gbogbo enia si duro tì ọ, lati owurọ̀ titi o fi di aṣalẹ?
15 Mose si wi fun ana rẹ̀ pe, Nitoriti awọn enia ntọ̀ mi wá lati bẽre lọwọ Ọlọrun ni:
16 Nigbati nwọn ba li ẹjọ́, nwọn a tọ̀ mi wá; emi a si ṣe idajọ larin ẹnikini ati ẹnikeji, emi a si ma mú wọn mọ̀ ìlana Ọlọrun, ati ofin rẹ̀.
17 Ana Mose si wi fun u pe, Eyiti iwọ nṣe nì kò dara.
18 Dajudaju iwọ o dá ara rẹ lagara, ati iwọ, ati awọn enia yi ti o pẹlu rẹ: nitoriti nkan yi wuwo jù fun ọ; iwọ nikan ki yio le ṣe e tikalarẹ.
19 Feti si ilẹ nisisiyi si ohùn mi; emi o fun ọ ni ìmọ, Ọlọrun yio si pẹlu rẹ: iwọ wà niwaju Ọlọrun fun awọn enia yi, ki iwọ ki o ma mú ọ̀ran wọn wá si ọdọ Ọlọrun.
20 Ki o si ma kọ́ wọn ni ìlana ati ofin wọnni, ki o si ma fi ọ̀na ti nwọn o ma rìn hàn fun wọn, ati iṣẹ ti nwọn o ma ṣe.
21 Pẹlupẹlu iwọ o si ṣà ninu gbogbo awọn enia yi awọn ọkọnrin ti o to, ti o bẹru Ọlọrun, awọn ọkọnrin olõtọ, ti o korira ojukokoro; irú awọn wọnni ni ki o fi jẹ olori wọn, lati ṣe olori ẹgbẹgbẹrun, ati olori ọrọrún, ati olori arãdọta, ati olori mẹwamẹwa.
22 Ki nwọn ki o si ma ṣe idajọ awọn enia nigbakugba: yio si ṣe, gbogbo ẹjọ́ nla ni ki nwọn ki o ma mú tọ̀ ọ wá, ṣugbọn gbogbo ẹjọ́ kekeké ni ki nwọn ki o ma dá: yio si rọrùn fun iwọ tikalarẹ, nwọn o si ma bá ọ rù ẹrù na.
23 Bi iwọ ba jẹ ṣe nkan yi, bi Ọlọrun ba si fi aṣẹ fun ọ bẹ̃, njẹ iwọ o le duro pẹ, ati gbogbo awọn enia yi pẹlu ni yio si dé ipò wọn li alafia.
24 Mose si gbà ohùn ana rẹ̀ gbọ́, o si ṣe ohun gbogbo ti o wi.
25 Mose si yàn awọn enia ti o to ninu gbogbo Israeli, o si fi wọn ṣe olori awọn enia, olori ẹgbẹgbẹrun, olori ọrọrún, olori arãdọta, olori mẹwamẹwa.
26 Nwọn si nṣe idajọ awọn enia nigbakugba: ọ̀ran ti o ṣoro, nwọn a mútọ̀ Mose wá, ṣugbọn awọn tikalawọn ṣe idajọ gbogbo ọ̀ran kekeké.
27 Mose si jẹ ki ana rẹ̀ ki o lọ; on si ba tirẹ̀ lọ si ilẹ rẹ̀.

## ORI 19.

LI oṣù kẹta, ti awọn ọmọ Israeli jade kuro ni ilẹ Egipti tán, li ọjọ́ na gan ni nwọn dé ijù Sinai.
2 Nwọn sá ti ṣí kuro ni Refidimu, nwọn si wá si ijù Sinai, nwọn si dó si ijù na; nibẹ̀ ni Israeli si dó si niwaju oke na.
3 Mose si goke tọ̀ Ọlọrun lọ, Oluwa si kọ si i lati oke na wá wipe, Bayi ni ki iwọ ki o sọ fun ile Jakobu, ki o si wi fun awọn ọmọ Israeli pe;
4 Enyin ti ri ohun ti mo ti ṣe si awọn ara Egipti, ati bi mo ti rù nyin li apa iyẹ́ idì, ti mo si mú nyin tọ̀ ara mi wa.
5 Njẹ nisisiyi, bi ẹnyin ba fẹ́ gbà ohùn mi gbọ́ nitõtọ, ti ẹ o si pa majẹmu mi mọ́, nigbana li ẹnyin o jẹ́ iṣura fun mi jù gbogbo enia lọ: nitori gbogbo aiye ni ti emi.
6 Ẹnyin o si ma jẹ́ ijọba alufa fun mi, ati orilẹ-ède mimọ́. Wọnyi li ọ̀rọ ti iwọ o sọ fun awọn ọmọ Israeli.
7 Mose si wá o si ranṣẹ pè awọn àgba awọn enia, o si fi gbogbo ọ̀rọ wọnyi lelẹ niwaju wọn ti Oluwa palaṣẹ fun u.
8 Gbogbo awọn enia na si jùmọ dahùn, nwọn si wipe, Ohun gbogbo ti Oluwa wi li awa o ṣe. Mose si mú ọ̀rọ awọn enia pada tọ̀ Oluwa lọ.
9 Oluwa si wi fun Mose pe, Wò o, emi tọ̀ ọ wá ninu awọsanma ṣíṣu, ki awọn enia ki o le ma gbọ́ nigbati mo ba mbá ọ sọ̀rọ, ki nwọn ki o si ma gbà ọ gbọ́ pẹlu lailai. Mose si sọ ọ̀rọ awọn enia na fun Oluwa.
10 Oluwa si wi fun Mose pe, Tọ̀ awọn enia yi lọ, ki o si yà wọn simimọ́ li oni ati li ọla, ki nwọn ki o si fọ̀ aṣọ wọn.
11 Ki nwọn ki o si mura dè ijọ́ kẹta: nitori ni ijọ́ kẹta Oluwa yio sọkalẹ sori oke Sinai li oju awọn enia gbogbo.
12 Ki iwọ ki o si sagbàra fun awọn enia

Digitized by Google

yiká, pe, Ẹ ma kiyesi ara nyin, ki ẹ máṣe gùn ori oke lọ, ki ẹ má si ṣe fọwọbà eti rẹ̀: ẹnikẹni ti o ba fọwọkàn oke na, pipa ni nitõtọ:
13 Ọwọkọwọ́ kò gbọdọ kàn a, bikoṣepe ki a sọ ọ li okuta, tabi ki a gún u pa nitõtọ; iba ṣe ẹranko iba ṣe enia, ki yio là a: nigbati ipè ba fun, ki nwọn ki o gùn oke wá.
14 Mose si sọkalẹ lati ori oke na wá sọdọ awọn enia, o si yà awọn enia si mimọ́, nwọn si fọ̀ aṣọ wọn.
15 O si wi fun awọn enia pe, Ẹ mura dè ijọ́ kẹta: ki ẹ máṣe sunmọ aya nyin.
16 O si ṣe, li owurọ̀ ijọ́ kẹta, ni ãrá ati mànamána wà, ati awọsanma ṣiṣu dùdu lori oke ina, ati ohùn ipè na si ndún kikankikan; tobẹ̃ ti gbogbo awọn ti o wà ni ibudó warìri.
17 Mose si mú awọn enia jade lati ibudó wá lati bá Ọlọrun pade; nwọn si duro ni ìha isalẹ oke na.
18 Oke Sinai si jẹ́ kìki ẽfi, nitoriti OLUWA sọkalẹ sori rẹ̀ ninu iná: ẽfi na si goke bi ẽfi ileru, gbogbo oke na si mìtiti.
19 O si ṣe ti ohùn ipè si dún, ti o si mulẹ kijikiji, Mose sọ̀rọ, Ọlọrun si fi ãrá da a li ohùn.
20 OLUWA si sọkalẹ wá si oke Sinai, lori oke na: OLUWA si pè Mose lori oke na; Mose si goke lọ.
21 OLUWA si wi fun Mose pe, Sọkalẹ, kìlọ fun awọn enia, ki nwọn ki o má ba yà sọdọ OLUWA lati bẹ̀ ẹ wọ̀, ki ọ̀pọ ki o má ba ṣegbe ninu wọn.
22 Si jẹ ki awọn alufa pẹlu, ti o sunmọ OLUWA, ki o yà ara wọn si mimọ́, ki OLUWA ki o má ba kọlù wọn.
23 Mose si wi fun OLUWA pe, Awọn enia ki yio le wá sori oke Sinai: nitoriti iwọ ti kìlọ fun wa pe, Sọ agbàra yi oke na ká, ki o si yà a si mimọ́.
24 OLUWA si wi fun u pe, Lọ, sọkalẹ; ki iwọ ki o si goke wá, iwọ ati Aaroni pẹlu rẹ: ṣugbọn ki awọn alufa ati awọn enia ki o máṣe yà lati goke tọ̀ OLUWA wá, ki o má ba kọlù wọn.
25 Bẹ̃ni Mose sọkalẹ tọ̀ awọn enia lọ, o si sọ̀rọ fun wọn.

## ORI 20.

OLỌRUN si sọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi pe,
2 Emi li OLUWA Ọlọrun rẹ, ti o mú ọ jade lati ilẹ Egipti, lati oko-ẹrú jade wá.
3 Iwọ kò gbọdọ lí ọlọrun miran pẹlu mi.
4 Iwọ kò gbọdọ yá ere fun ara rẹ, tabi aworan ohun kan ti mbẹ loke ọrun, tabi ti ohun kan ti mbẹ ni isalẹ ilẹ, tabi ti ohun kan ti mbẹ ninu omi ni isale ilẹ.
5 Iwọ kò gbọdọ tẹ̀ ori ara rẹ ba fun wọn, bẹ̃ni iwọ kò gbọdọ sìn wọn: nitori emi li OLUWA Ọlọrun rẹ, Ọlọrun owú ni mi, ti mbẹ̀ ẹ̀ṣẹ awọn baba wò lara awọn ọmọ, lati irandiran kẹta ati ẹkẹrin ninu awọn ti o korira mi;
6 Emi a si ma fi ãnu hàn ẹgbẹgbẹrun awọn ti o fẹ́ mi, ti nwọn si npa ofin mi mọ́.
7 Iwọ kò gbọdọ pè orukọ OLUWA Ọlọrun rẹ lasan; nitoriti OLUWA ki yio mu awọn ti o pè orukọ rẹ̀ lasan bi alailẹ̀ṣẹ li ọrùn.
8 Ranti ọjọ́ isimi, lati yà a simimọ́.
9 Ọjọ́ mẹfa ni iwọ o ṣiṣẹ, ti iwọ o si ṣe iṣẹ rẹ gbogbo:
10 Ṣugbọn ọjọ́ keje li ijọ́ isimi OLUWA Ọlọrun rẹ: ninu rẹ̀ iwọ kò gbọdọ ṣe iṣẹkiṣẹ kan, iwọ, ati ọmọ rẹ ọkọnrin, ati ọmọ rẹ obirin, ọmọ-ọdọ rẹ ọkọnrin, ati ọmọ-ọdọ rẹ obirin, ohunọ̀sin rẹ, ati alejò rẹ ti mbẹ ninu ibode rẹ:
11 Nitori ni ijọ́ mẹfa li OLUWA dá ọrun on aiye, okun ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu wọn, o si simi ni ijọ́ keje: nitorina li OLUWA ṣe busi ijọ́ keje, o si yà a si mimọ́.
12 Bọ̀wọ fun baba on iya rẹ: ki ọjọ́ rẹ ki o le pẹ ni ilẹ ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ.
13 Iwọ kò gbọdọ pania.
14 Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga.
15 Iwọ kò gbọdọ jale.
16 Iwọ kò gbọdọ jẹri eke si ẹnikeji rẹ.
17 Iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro si ile ẹnikeji rẹ, iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro si aya ẹnikeji rẹ, tabi si ọmọ-ọdọ rẹ̀ ọkọnrin, tabi ọmọ-ọdọ rẹ̀ obirin, akọmalu rẹ̀, kẹtẹkẹtẹ rẹ̀, tabi ohun gbogbo ti iṣe ti ẹnikeji rẹ.
18 Gbogbo awọn enia na si ri ãrá na, ati mànamána na, ati ohùn ipè na, nwọn ri oke na nṣe ẽfi: nigbati awọn enia si ri i, nwọn ṣí, nwọn duro li òkere rére.
19 Nwon si wi fun Mose pe, Iwọ ma bá wa sọ̀rọ, awa o si gbọ́: ṣugbọn máṣe jẹ ki Ọlọrun ki o bá wa sọ̀rọ, ki awa ki o má ba kú.
20 Mose si wi fun awọn enia pe, Ẹ má bẹ̀ru: nitoriti Ọlọrun wá lati dan nyin wò, ati ki ẹ̀ru rẹ̀ ki o le ma wà li oju nyin, ki ẹnyin ki o máṣe ṣẹ̀.
21 Awọn enia si duro li òkere rére, Mose si sunmọ ibi òkunkun ṣiṣu na nibiti Ọlọrun gbé wà.
22 OLUWA si wi fun Mose pe, Bayi ni ki iwọ ki o wi fun awọn ọmọ Israeli pe,

Digitized by Google

Ẹnyin ri bi emi ti bá nyin sọ̀rọ lati ọrun
wá.
23 Ẹnyin kò gbọdọ ṣe ọlọrun miran pẹlu
mi; Ẹnyin kò gbọdọ ṣe ọlọrun fadaka, tabi
ọlọrun wurà, fun ara nyin.
24 Pẹpẹ erupẹ ni ki iwọ mọ fun mi, lori
rẹ̀ ni ki iwọ ki o ma ru ẹbọ sisun rẹ, ati
ẹbọ alafia rẹ, agutan rẹ, ati akọmalu rẹ: ni
ibi gbogbo ti mo ba gbé fi iranti orukọ mi
si, emi o ma tọ̀ ọ wá, emi o si ma bukún
fun ọ.
25 Bi iwọ o ba si mọ pẹpẹ okuta fun mi,
iwọ kò gbọdọ fi okuta gbigbẹ́ mọ ọ: nitori
bi iwọ ba gbé ohun-ọnà rẹ lé ori rẹ̀, iwọ sọ
ọ di aimọ́.
26 Iwọ kò si gbọdọ ba àkasọ gùn ori pẹ-
pẹ mi, ki ìhoho rẹ ki o máṣe hàn lori rẹ̀.

## ORI 21.

NJẸ wọnyi ni idajọ ti iwọ o gbekalẹ ni-
waju wọn.
2 Bi iwọ ba rà ọkọnrin Heberu li ẹrú,
ọdún mẹfa ni on o sìn: li ọdún keje yio si
jade bi omnira lọfẹ.
3 Bi o ba nikan wọle wá, on o si nikan
jade lọ: bi o ba ti gbé iyawo, njẹ ki aya
rẹ̀ ki o bá a jade lọ.
4 Bi o ba ṣepe oluwa rẹ̀ li o fun u li aya,
ti on si bí ọmọkọnrin tabi ọmọbirin fun u;
aya ati awọn ọmọ ni yio jẹ́ ti oluwa rẹ̀, on
tikara rẹ̀ yio si nikan jade lọ.
5 Bi ẹru na ba si wi ni gbangba pe, Emi
fẹ́ oluwa mi, aya mi, ati awọn ọmọ mi;
emi ki yio jade lọ idi omnira:
6 Nigbana ni ki oluwa rẹ̀ ki o mú u lọ
sọdọ awọn onidajọ; yio si mú u lọ si ẹnu-
ọ̀na, tabi si opó ẹnu-ọ̀na; oluwa rẹ̀ yio si fi
olù lú u li eti; on a si ma sìn i titi aiye.
7 Bi ẹnikan ba si tà ọmọ rẹ̀ obirin li ẹrú,
on ki yio jade lọ bi awọn ẹrú ọkọnrin ti i-
jade lọ.
8 Bi on kò ba wù oluwa rẹ̀, ti o ti fẹ́ ẹ
fun ara rẹ̀, njẹ ki o jẹ ki a rà a pada, on ki
yio lagbara lati tà a fun ajeji enia, o sa ti
tàn a jẹ.
9 Bi o ba si fẹ́ ẹ fun ọmọkọnrin rẹ̀, ki o
ma ṣe si i bi a ti iṣe si ọmọbirin ẹni.
10 Bi o ba si fẹ́ obirin miran; onjẹ rẹ̀,
aṣọ rẹ̀, ati iṣe ọkọlaya rẹ̀, ki o máṣe yẹ̀.
11 Bi on ki yio ba si ṣe ohun mẹtẹta yi
fun u, njẹ ki on ki o jade kuro lọfẹ li ai-
san owo.
12 Ẹniti o ba lù enia, tobẹ̃ ti o si ku,
pipa li o pa a.
13 Bi o ba ṣepe enia kò ba dèna, ṣugbọn
ti o ṣepe Ọlọrun li o fi lé e lọwọ, njẹ emi o
yàn ibi fun ọ, nibiti on o gbé salọ si.
14 Ṣugbọn bi enia ba ṣika si aladugbo rẹ̀,
lati fi ẹ̀tan pa a; ki iwọ ki o tilẹ mú u lati
ibi pẹpẹ mi lọ, ki o le kú.
15 Ẹniti o ba si lù baba, tabi iya rẹ̀,
pipa li a o pa a.
16 Ẹniti o ba si jí enia, ti o si tà a, tabi
ti a ri i li ọwọ́ rẹ̀, pipa li a o pa a.
17 Ẹniti o ba si bú baba tabi iya rẹ̀, pipa
li a o pa a.
18 Bi awọn ọkọnrin ba si jùmọ njà, ti
ekini fi okuta lù ekeji, tabi ti o jìn i li ẹ̀ṣẹ́,
ti on kò si kú, ṣugbọn ti o da a bulẹ:
19 Bi o ba si tun dide, ti o ntẹ̀ ọpá rìn
kiri ni ita, nigbana li ẹniti o lù u yio to
bọ́; kìki gbèse akokò ti o sọnù ni yio san,
on o si ṣe ati mu u lara da ṣaṣa.
20 Bi ẹnikan ba si fi ọpá lù ẹrú rẹ̀ ọkọn-
rin tabi obirin, ti o si kú si i li ọwọ́, a o
gbẹsan rẹ̀ nitõtọ.
21 Ṣugbọn bi o ba duro di ijọ́ kan, tabi
meji, a ki yio gbẹsan rẹ̀: nitoripe owo rẹ̀
ni iṣe.
22 Bi awọn ọkọnrin ba njà, ti nwọn si
pa obirin aboyún lara, tobẹ̃ ti oyún rẹ̀ ṣé,
ṣugbọn ti ibi miran kò sí pẹlu: a o mu ki
o san nitõtọ, gẹge bi ọkọ obirin na yio ti
dá lé e; on o si san a niwaju onidajọ.
23 Bi ibi kan ba si pẹlu, njẹ ki iwọ ki o
fi ẹmi dipò ẹmi.
24 Fi oju dipò oju, ehín dipò ehín, ọwọ́
dipò ọwọ́, ẹsẹ̀ dipò ẹsẹ̀.
25 Fi ijóna dipò ijóna, ọgbẹ́, dipò ọgbẹ́,
ìna dipò ìna.
26 Bi o ba ṣepe ẹnikan ba lù ẹrú rẹ̀ ọkọn-
rin tabi ẹrú rẹ̀ obirin li oju ti o si fọ́; ki
o si jọwọ rẹ̀ lọ li omnira nitori oju rẹ̀.
27 Bi o ba si ká ehín ẹrú rẹ̀ ọkọnrin,
tabi ehín ẹrú rẹ̀ obirin; ki o si jọwọ rẹ̀ lọ
li omnira nitori ehín rẹ̀.
28 Bi akọmalu ba kàn ọkọnrin tabi obi-
rin ti o si kú: sisọ ni ki a sọ akọmalu na
li okuta pa bi o ti wù ki o ṣe, ki a má si ṣe
jẹ ẹran rẹ̀; ṣugbọn ọrùn oni-akọmalu na yio
mọ́.
29 Ṣugbọn bi o ba ṣepe akọmalu na, a ti
ma fi iwo rẹ̀ kàn nigba atijọ, ti a si ti kìlọ
fun oluwa rẹ̀, ti kò si sé e mọ, ṣugbọn ti o
pa ọkọnrin tabi obirin, akọmalu na li a o
sọ li okuta pa, oluwa rẹ̀ li a o si lù pa pẹlu.
30 Bi o ba si ṣepe a bù iye owo kan fun
u, njẹ iyekiye ti a bù fun u ni yio fi ṣe ira-
pada ẹmi rẹ̀.
31 Iba kàn ọmọkọnrin, tabi iba kàn ọmọ-
birin, gẹgẹ bi irú idajọ yi li a o ṣe si i.

Digitized by Google

32 Bi akọmalu na ba kan ẹrukọnrin tabi ẹrubirin; on o si san ọgbọn ṣekeli fadakà fun oluwa rẹ̀, a o si sọ akọmalu na li okuta pa.

33 Bi ẹnikan ba ṣí ihò silẹ, tabi bi ọkọnrin kan ba si wà ihò silẹ, ti kò si bò o, ti akọmalu tabi kẹtẹkẹtẹ ba bọ́ sinu rẹ̀;

34 Oni-ihò na yio si san; yio si fi owo fun oluwa wọn; okú ẹran a si jẹ́ tirẹ̀.

35 Bi akọmalu ẹnikan ba si pa akọmalu ẹnikeji lara ti o si kú; ki nwọn ki o tà ãye akọmalu, ki nwọn ki o si pín owo rẹ̀; oku ni ki nwọn ki o si pín pẹlu.

36 Tabi bi a ba si mọ̀ pe akọmalu na a ti ma kàn nigba atijọ ti oluwa rẹ̀ kò sé e mọ́; on o fi akọmalu san akọmalu nitõtọ; okú a si jẹ́ tirẹ̀.

## ORI 22.

BI ọkọnrin kan ba jí akọmalu, tabi agutan kan, ti o si pa a, tabi ti o tà a; yio san akọmalu marun dipò akọmalu kan, ati agutan mẹrin dipò agutan kan.

2 Bi a ba ri olè ti nrunlẹ wọle, ti a si lù u ti o kú, a ki yio ta ẹ̀jẹ silẹ fun u.

3 Bi õrùn ba là bá a, a o ta ẹ̀jẹ silẹ fun u; sisan li on iba san; bi kò ní nkan, njẹ a o tà a nitori olè rẹ̀.

4 Bi a ba ri ohun ti o jí na li ọwọ́ rẹ̀ nitõtọ li ãye, iba ṣe akọmalu, tabi kẹtẹkẹtẹ, tabi agutan; on o san a pada ni meji.

5 Bi ọkọnrin kan ba mu ki a jẹ oko tabi agbalá-àjara kan, ti o si tú ẹran rẹ̀ silẹ, ti o si jẹ li oko ẹlomiran; ninu ãyo oko ti ara rẹ̀, ati ninu ãyo agbalá-àjara tirẹ̀, ni yio fi san ẹsan.

6 Bi iná ba ṣẹ́, ti o si mu ẹwọn, ti abà ọkà, tabi ọkà aiṣá, tabi oko li o joná; ẹniti o ràn iná na yio san ẹsan nitõtọ.

7 Bi ẹnikan ba fi owo tabi ohunèlo fun ẹnikeji rẹ̀ pamọ́; ti a jí i ni ile ọkọnrin na; bi a ba mu olè na, ki o san a ni meji.

8 Bi a kò ba mú olè na, njẹ ki a mú bale na wá siwaju awọn onidajọ, bi on kò ba fọwọkàn ẹrù ẹnikeji rẹ̀.

9 Nitori irú ẹ̀ṣẹ gbogbo, iba ṣe ti akọmalu, ti kẹtẹkẹtẹ, ti agutan, ti aṣọ, tabi ti irũru ohun ti o nù, ti ẹlomiran pè ni ti on, ẹjọ́ awọn mejeji yio wá siwaju awọn onidajọ; ẹniti awọn onidajọ ba dẹbi fun, on o san a ni iṣẹmeji fun ẹnikeji rẹ̀.

10 Bi enia ba fi kẹtẹkẹtẹ, tabi akọmalu, tabi agutan, tabi ẹrankẹran lé ẹnikeji rẹ̀ lọwọ lati ma sìn; ti o ba si kú, tabi ti o farapa, tabi ti a lé e sọnù, ti ẹnikan kò ri i;

11 Ibura OLUWA yio wà lãrin awọn mejeji, pe, on kò fọwọkàn ẹrù ẹnikeji on; ki on ki o si gbà, on ki yio si san ẹsan,

12 Bi o ba ṣepe a jí i lọwọ rẹ̀, on o san ẹsan fun oluwa rẹ̀.

13 Bi o ba ṣepe a si fà a ya, njẹ ki o mú u wa ṣe ẹrí, on ki yio si san ẹsan eyiti a fàya.

14 Bi enia ba si wín ohun kan lọwọ ẹnikeji rẹ̀, ti o si farapa, tabi ti o kú, ti olohun kò sí nibẹ̀, on o san ẹsan nitõtọ.

15 Ṣugbọn bi olohun ba wà nibẹ̀, on ki yio san ẹsan: bi o ba ṣe ohun ti a fi owo gbà lò ni, o dé fun owo igbàlo rẹ̀.

16 Bi ọkọnrin kan ba si tàn wundia kan ti a kò ti ifẹ́, ti o si mọ̀ ọ, fifẹ́ ni yio si fẹ́ ẹ li aya rẹ̀.

17 Bi baba rẹ̀ ba kọ̀ jalẹ lati fi i fun u, on o san ojì gẹgẹ bi ifẹ́ wundia.

18 Iwọ kò gbọdọ jẹ ki ajẹ́ ki o wà lãye.

19 Ẹnikẹni ti o ba bá ẹranko dàpọ pipa li a o pa a.

20 Ẹnikẹni ti o ba rubọ si oriṣakoriṣa, bikoṣe si JEHOFA nikanṣoṣo, a o pa a run tútu.

21 Iwọ kò gbọdọ ṣìka si alejò, bẹ̃ni iwọ kò gbọdọ ni i lara: nitoripe alejò li ẹnyin ti jẹ́ ni ilẹ Egipti.

22 Ẹnyin kò gbọdọ jẹ opó ni ìya, tabi ọmọ alainibaba.

23 Bi iwọ ba jẹ wọn ni ìyakiya, ti nwọn si kigbe pè mi, emi o gbọ́ igbe wọn nitõtọ.

24 Ibinu mi yio si gboná, emi o si fi idà pa nyin; awọn aya nyin yio si di opó, awọn ọmọ nyin a si di alainibaba.

25 Bi iwọ ba wín ẹnikẹni ninu awọn enia mi li owo ti o ṣe talaka lọdọ rẹ, iwọ ki yio jẹ́ bi agbẹ̀da fun u; bẹ̃ni iwọ ki yio gbẹ̀da lọwọ rẹ̀.

26 Bi o ba ṣepe iwọ gbà aṣọ ẹnikeji rẹ ṣe ògo, ki iwọ ki o si fi i fun u, ki õrùn to wọ̀:

27 Nitori kìki eyi ni ibora rẹ̀, aṣọ rẹ̀ ti yio fi bora ni: kini on o fi bora sùn? yio si ṣe bi o ba kigbe pè mi, emi o gbọ́; nitori alãnu li emi.

28 Iwọ kò gbọdọ gàn awọn onidajọ, bẹ̃ni iwọ kò gbọdọ bú ijoye kan ninu awọn enia rẹ.

29 Iwọ kò gbọdọ jafara lati mú irè oko rẹ wá, ati ọti rẹ. Akọ́bi awọn ọmọ rẹ ọkọnrin ni iwọ o fi fun mi.

30 Bẹ̃ gẹgẹ ni ki iwọ ki o fi akọmalu ati agutan rẹ ṣe: ijọ́ meje ni ki o ba iya rẹ̀ gbé; ni ijọ́ kẹjọ ni ki iwọ ki o fi fun mi.

31 Ẹnyin o si jẹ́ enia mimọ́ fun mi;

Digitized by Google

nitorina ẹnyin kò gbọdọ jẹ ẹran ti a ti ẹranko igbẹ́ fàya ; ajá ni ki ẹnyin ki o wọ́ ọ fun.

## ORI 23.

IWỌ kò gbọdọ gbà ìhin eke : máṣe li ọwọ́ si i pẹlu enia buburu lati ṣe ẹlẹri aiṣododo.

2 Iwọ kò gbọdọ tọ̀ ọ̀pọlọpọ enia lẹhin lati ṣe ibi, bẽni iwọ kò gbọdọ sọrọ li ọ̀ran ki o tẹ̀ si ọ̀pọ enia lati yi ẹjọ́ po.

3 Bẽni iwọ kò gbọdọ gbè talaka li ẹjọ́ rẹ̀.

4 Bi iwọ ba bá akọmalu tabi kẹtẹkẹtẹ ọtá rẹ ti o ṣina, ki iwọ ki o mú u pada fun u wá nitõtọ.

5 Bi iwọ ba ri kẹtẹkẹtẹ ẹniti o korira rẹ, ti o dubulẹ labẹ ẹrù rẹ̀, ti iwọ iba yẹra lati bá a tú u, iwọ o bá a tú u nitõtọ.

6 Iwọ kò gbọdọ yi ẹjọ́ talaka rẹ po li ọ̀ran rẹ̀.

7 Takète li ọ̀ran eke ; ati alaiṣẹ ati olododo ni iwọ kò gbọdọ pa : nitoriti emi ki yio dá enia buburu lare.

8 Iwọ kò gbọdọ gbà ọrẹ : nitori ọrẹ ni ifọ́ awọn ti o riran loju, a si yi ọ̀ran awọn olododo po.

9 Ati pẹlu iwọ kò gbọdọ pọ́n alejò kan loju : ẹnyin sa ti mọ̀ inu alejò, nitoriti ẹnyin ti jẹ́ alejò ni ilẹ Egipti.

10 Ọdún mẹfa ni iwọ o si gbìn ilẹ rẹ, on ni iwọ o si kó eso rẹ̀ jọ.

11 Ṣugbọn li ọdún keje iwọ o jẹ ki o simi, ki o si gbé jẹ ; ki awọn talaka enia rẹ ki o ma jẹ ninu rẹ̀ : eyiti nwọn si fisilẹ ni ki ẹran igbẹ ki o ma jẹ. Irú bẽ gẹgẹ ni iwọ o ṣe si agbalá-àjara, ati agbalá-olifi rẹ.

12 Ijọ́ mẹfa ni iwọ o ṣe iṣẹ rẹ, ni ijọ́ keje ki iwọ ki o si simi : ki akọmalu rẹ, ati kẹtẹkẹtẹ rẹ ki o le simi, ki a le tù ọmọ iranṣẹbirin rẹ, ati alejò, lara.

13 Ati li ohun gbogbo ti mo wi fun nyin, ẹ ma ṣọra : ki ẹ má si ṣe iranti orukọ oriṣakoriṣa, ki a má ṣe gbọ́ ọ li ẹnu nyin.

14 Ni ìgba mẹta ni iwọ o ṣe ajọ fun mi li ọdún.

15 Iwọ o kiyesi ajọ aiwukàra : ijọ́ meje ni iwọ o fi jẹ àkara alaiwu, bi mo ti pa a laṣẹ fun ọ, li akokò oṣù Abibu (nitori ninu rẹ̀ ni iwọ jade kuro ni Egipti) ; a kò gbọdọ ri ẹnikan niwaju mi li ọwọ́ ofo :

16 Ati ajọ ikore, akọ́so iṣẹ rẹ, ti iwọ gbìn li oko rẹ : ati ajọ ikore oko, li opin ọdún, nigbati iwọ ba ṣe ikore iṣẹ oko rẹ tán.

17 Ni ìgba mẹta li ọdún ni gbogbo awọn ọkọnrin rẹ yio farahàn niwaju Oluwa JEHOFA.

18 Iwọ kò gbọdọ ta ọrẹ ẹ̀jẹ ẹbọ mi ti on ti àkara wiwu ; bẽli ọrá ẹbọ ajọ mi kò gbọdọ kù titi di ojumọ́.

19 Akọ́ka eso ilẹ rẹ ni ki iwọ ki o múwa si ile OLUWA Ọlọrun rẹ. Iwọ ko gbọdọ bọ̀ ọmọ ewurẹ ninu warà iya rẹ̀.

20 Kiyesi i, emi rán angeli kan siwaju rẹ lati pa ọ mọ́ li ọ̀na, ati lati mú ọ dé ibi ti mo ti pèse silẹ.

21 Kiyesi ara lọdọ rẹ̀, ki o si gbà ohùn rẹ̀ gbọ́, máṣe bi i ninu ; nitoriti ki yio dari irekọja nyin jì nyin, nitoriti orukọ mi mbẹ lara rẹ̀.

22 Ṣugbọn bi iwọ o ba gbà ohùn rẹ̀ gbọ́ nitõtọ, ti iwọ si ṣe gbogbo eyiti mo wi ; njẹ emi o jasi ọtá awọn ẹniti nṣe ọtá nyin, emi o si foró awọn ti nforó nyin.

23 Nitoriti angeli mi yio ṣaju rẹ, yio si mú ọ dé ọdọ awọn enia Amori, ati awọn Hitti, ati awọn Perissi, ati awọn ara Kenaani, awọn Hifi, ati awọn Jebusi : emi a si ke wọn kuro.

24 Iwọ kò gbọdọ tẹriba fun oriṣa wọn, bẽni iwọ kò gbọdọ sìn wọn, ki o má si ṣe gẹgẹ bi iṣe wọn : bikoṣepe ki iwọ ki o fọ́ wọn tútu, ki iwọ ki o si wó ere wọn palẹ.

25 Ẹnyin o si ma sìn OLUWA Ọlọrun nyin, on o si busi onjẹ rẹ, ati omi rẹ ; emi o si mú àrun kuro lãrin rẹ.

26 Obirin kan ki yio ṣẹ́nu, bẽni ki yio yàgan ni ilẹ rẹ : iye ọjọ́ rẹ li emi o kún.

27 Emi o rán ẹ̀ru mi siwaju rẹ, emi o si dà gbogbo awọn enia rú ọdọ ẹniti iwọ o dé, emi o si mu gbogbo awọn ọtá rẹ yi ẹ̀hin wọn dà si ọ.

28 Emi o si rán agbọ́n siwaju rẹ, ti yio lé awọn enia Hifi, ati awọn ara Kenaani, ati awọn enia Hitti kuro niwaju rẹ.

29 Emi ki yio lé wọn jade kuro niwaju rẹ li ọdún kan ; ki ilẹ na ki o má ba di ijù, ki ẹranko igbẹ́ ki o má ba rẹ̀ si ọ.

30 Diẹdiẹ li emi o ma lé wọn jade kuro niwaju rẹ, titi iwọ o fi di pupọ̀, ti iwọ o si tẹ̀ ilẹ na dó.

31 Emi o si fi opinlẹ rẹ lelẹ, lati Okun Pupa wá titi yio fi dé okun awọn ara Filistia, ati lati aṣalẹ̀ nì wá dé odò nì ; nitoriti emi o fi awọn olugbe ilẹ na lé nyin lọwọ ; iwọ o si lé wọn jade kuro niwaju rẹ.

32 Iwọ kò gbọdọ bá wọn ṣe adehùn, ati awọn oriṣa wọn pẹlu.

33 Nwọn kò gbọdọ joko ni ilẹ rẹ, ki nwọn ki o má ba mu ọ ṣẹ̀ si mi : nitori bi iwọ ba sìn oriṣa wọn, yio ṣe idẹkùn fun ọ nitõtọ.

Digitized by Google

## ORI 24.

O SI wi fun Mose pe, Goke tọ̀ OLUWA wá, iwọ, ati Aaroni, Nadabu, ati Abihu, ati ãdọrin ninu awọn àgba Israeli ; ki ẹnyin ki o si ma sìn li òkere rére.

2 Mose nikanṣoṣo ni yio si sunmọ OLUWA ; ṣugbọn awọn wọnyi kò gbọdọ sunmọ tosi ; bẹ̃li awọn enia kò gbọdọ bá a gòke lọ.

3 Mose si wá o si sọ gbogbo ọ̀rọ OLUWA, ati gbogbo idajọ fun awọn enia : gbogbo enia si fi ohùn kan dahùn wipe, Gbogbo ọ̀rọ ti OLUWA wi li awa o ṣe.

4 Mose si kọwe gbogbo ọ̀rọ OLUWA, o si dide ni kùtukutu owurọ̀, o si tẹ́ pẹpẹ kan nisalẹ òke na, o mọ ọwọ̀n mejila, gẹgẹ bi ẹ̀ya Israeli mejila.

5 O si rán awọn ọdọmọkọnrin ninu awọn ọmọ Israeli, nwọn si ru ẹbọ sisun, nwọn si fi akọmalu ru ẹbọ alafia si OLUWA.

6 Mose si mú àbọ ẹ̀jẹ na o si fi i sinu awokòto ; ati àbọ ẹ̀jẹ na o fi wọ́n ara pẹpẹ na.

7 O si mú iwé majẹmu nì, o si kà a li eti awọn enia : nwọn si wipe, Gbogbo eyiti OLUWA wi li awa o ṣe, awa o si gbọràn.

8 Mose si mú ẹ̀jẹ na, o si wọ́n ọ sara awọn enia, o si wipe, Kiyesi ẹ̀jẹ majẹmu, ti OLUWA bá nyin dá nipasẹ ọ̀rọ gbogbo wọnyi.

9 Nigbana ni Mose, ati Aaroni, Nadabu, ati Abihu, ati ãdọrin ninu awọn àgba Israel, gòke lọ :

10 Nwọn si ri Ọlọrun Israeli ; bi iṣẹ okuta Safire wà li abẹ ẹsẹ̀ rẹ̀, o si dabi irisi ọrun ni imọ́toto rẹ̀.

11 Kò si nà ọwọ́ rẹ̀ lé awọn ọlọlá ọmọ Israel : nwọn si ri Ọlọrun, nwọn si jẹ, nwọn si mu.

12 OLUWA si wi fun Mose pe, Gòke tọ̀ mi wá sori òke, ki o si duro nibẹ̀ ; emi o si fi walã okuta fun ọ, ati aṣẹ kan, ati ofin ti mo ti kọ, ki iwọ ki o le ma kọ́ wọn.

13 Mose si dide, ati Joṣua iranṣẹ rẹ̀ : Mose si gòke lọ si oke Ọlọrun.

14 O si wi fun awọn àgba na pe, Ẹ duro dè wa nihinyi, titi awa o fi tun pada tọ̀ nyin wá : si kiyesi i, Aaroni ati Huri mbẹ pẹlu nyin : bi ẹnikan ba li ọ̀ran kan, ki o tọ̀ wọn wá.

15 Mose si gòke lọ sori òke na, awọsanma si bò òke na mọlẹ.

16 Ogo OLUWA si sọkalẹ sori òke Sinai, awọsanma na si bò o mọlẹ ni ijọ́ mẹfa : ni ijọ́ keje o ké si Mose lati ãrin awọsanma wá.

17 Iwò ogo OLUWA dabi iná ajonirun li ori òke na li oju awọn ọmọ Israeli.

18 Mose si lọ sãrin awọsanma na, o si gùn ori òke na : Mose si wà lori òke li ogoji ọsán ati ogoji oru.

## ORI 25.

OLUWA si sọ fun Mose pe,

2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, ki nwọn ki o mú ọrẹ fun mi wá : lọwọ olukuluku enia ti o ba fifunni tinutinu ni ki ẹnyin ki o gbà ọrẹ mi.

3 Eyi si li ọrẹ ti ẹnyin o gbà lọwọ wọn ; wurà, ati fadakà, ati idẹ ;

4 Ati aṣọ-alaró, ati elesè-àlukọ, ati ododó, ati ọ̀gbọ, ati irun ewurẹ ;

5 Ati awọ àgbo ti a se ni pupa, ati awọ seali, ati igi ṣittimu.

6 Oróro fun fitila, olõrùn fun oróro itasori, ati fun turari didùn ;

7 Okuta oniki, ati okuta ti a o tò si ẹ̀wu-efodi, ati si igbàiya.

8 Ki nwọn ki o si ṣe ibi mimọ́ kan fun mi ; ki emi ki o le ma gbé ãrin wọn.

9 Gẹgẹ bi gbogbo eyiti mo fihàn ọ, nipa apẹrẹ agọ́, ati apẹrẹ gbogbo ohunèlo inu rẹ̀, bẹ̃ni ki ẹnyin ki o si ṣe e.

10 Nwọn o si ṣe apoti igi ṣittimu : igbọnwọ meji on àbọ ni gigùn rẹ̀, ati igbọnwọ kan on àbo ni ibú rẹ̀, ati igbọnwọ kan on àbọ ni giga rẹ̀.

11 Iwọ o si fi kìki wurà bò o, ninu ati lode ni iwọ o fi bò o, iwọ o si ṣe igbáti wurà sori rẹ̀ yiká.

12 Iwọ o si ṣe oruka wurà mẹrin si i, iwọ o si fi wọn si igun mẹrin rẹ̀ ; oruka meji yio si wà li apa kini rẹ̀, oruka meji yio si wà li apa keji rẹ̀.

13 Iwọ o si ṣe ọpá ṣittimu, ki iwọ ki o si fi wurà bọ wọn.

14 Iwọ o si fi ọpá wọnni bọ̀ inu oruka wọnni ni ìha apoti na, ki a le ma fi wọn gbé apoti na.

15 Ọpá wọnni yio si ma wà ninu oruka apoti na : a ki yio si yọ wọn kuro ninu rẹ̀.

16 Iwọ o si fi ọri ti emi o fi fun ọ sinu apoti nì.

17 Iwọ o si fi kìki wurà ṣe itẹ́-ãnu : igbọnwọ meji on àbọ ni gigùn rẹ̀, ati igbọnwọ kan on àbọ ni ibú rẹ̀.

18 Iwọ o si ṣe kerubu wurà meji ; ni iṣẹ lilù ni ki iwọ ki o fi ṣe wọn, ni ìku itẹ́-ãnu na mejeji.

19 Si ṣe kerubu kini ni ìku kan, ati kerubu keji ni ìku keji : lati itẹ́-ãnu ni ki

Digitized by Google

ẹnyin ki o ṣe awọn kerubu na ni ìku rẹ̀
mejeji.
20 Awọn kerubu na yio si nà iyẹ́-apa
wọn si oke, ki nwọn ki o fi iyẹ́-apa wọn bò
itẹ́-ãnu na, ki nwọn ki o si kọjusi ara wọn ;
itẹ́-ãnu na ni ki awọn kerubu na ki o
kọjusi.
21 Iwọ o si fi itẹ́-ãnu na sori apoti na ;
ati ninu apoti na ni iwọ o fi ẹri ti emi o fi
fun ọ si.
22 Nibẹ̀ li emi o ma pade rẹ, emi o si
ma bá ọ sọrọ lati oke itẹ́-ãnu wá, lati ãrin
awọn kerubu mejeji wá, ti o wà lori apoti
ẹrí na, niti ohun gbogbo ti emi o palaṣẹ
fun ọ si awọn ọmọ Israeli.
23 Iwọ o si ṣe tabili igi ṣittimu kan :
igbọnwọ meji ni gigùn rẹ̀, ati igbọnwọ kan
ni ibú rẹ̀, ati igbọnwọ kan on àbọ ni giga rẹ̀.
24 Iwọ o si fi kìki wurà bò o, iwọ o si ṣe
igbáti wurà si i yiká.
25 Iwọ o si ṣe eti kan bi ibú-atẹlẹwọ
si i yiká, iwọ o si ṣe igbáti wurà si eti rẹ̀
yiká.
26 Iwọ o si ṣe oruka wurà mẹrin si i, iwọ
o si fi oruka wọnni si igun mẹrẹrin, ti o wà
li ẹsẹ̀ rẹ̀ mẹrẹrin.
27 Li abẹ igbáti na li oruka wọnni yio
wà, fun ibi ọpá lati ma fi rù tabili na.
28 Iwọ o si ṣe ọpá igi ṣittimu, iwọ o si fi
wurà bò wọn, ki a le ma fi wọn rù tabili na.
29 Iwọ o si ṣe awopọkọ rẹ̀, ati ṣibi rè,
ati ìgo rẹ̀, ati awo rẹ̀, lati ma fi dà : kìki
wurà ni ki iwọ ki o fi ṣe wọn.
30 Iwọ o si ma gbé àkara ifihàn kalẹ lori
tabili na niwaju mi nigbagbogbo.
31 Iwọ o si fi kìki wurà ṣe ọpá fitila kan :
iṣẹlilù li a o fi ṣe ọpá-fitila na, ipilẹ rẹ̀, ọpá
rẹ̀ ; ago rẹ̀, irudi rẹ̀, ati itanna rẹ̀, ọkanna
ni nwọn o jẹ́ :
32 Ẹka mẹfa ni yio yọ ni ìha rẹ̀ ; ẹka
mẹta ọpá-fitila na ni ìha kan, ati ẹka mẹta
ọpá-fitila na ni ìha keji :
33 Ago mẹta ni ki a ṣe bi itanna almondi,
pẹlu irudi ati itanna li ẹka kan ; ati ago
mẹta ti a ṣe bi itanna almondi li ẹka ekeji,
pẹlu irudi ati itanna : bẽli ẹka mẹfẹfa ti o
yọ lara ọpá-fitila na.
34 Ati ninu ọpá-fitila na li ago mẹrin
yio wà ti a ṣe bi itanna almondi, pẹlu
irudi wọn ati itanna wọn.
35 Irudi kan yio si wà nisalẹ ẹka rẹ̀ meji
ki o ri bakanna, irudi kan yio si wà nisalẹ
ẹka rẹ̀ meji ki o ri bakanna, irudi kan yio si
wà nisalẹ ẹka rẹ̀ meji ki o ri bakanna, gẹgẹ
bi ẹka rẹ̀ mẹfẹfa ti o ti ara ọpá-fitila na yọ
jade.
36 Irudi wọn ati ẹka wọn ki o ri
bakanna : ki gbogbo rẹ̀ ki o jẹ́ lilù kìki
wurà kan.
37 Iwọ o si ṣe fitila rẹ̀ na, meje : ki
nwọn ki o si fi fitila wọnni sori rẹ̀, ki nwọn
ki o le ma ṣe imọlẹ si iwaju rẹ̀.
38 Ati alumagaji rẹ̀, ati awo alumagaji
rẹ̀, kìki wurà ni ki o jẹ́.
39 Talenti kan kìki wurà ni ki o fi ṣe e,
pẹlu gbogbo ohunèlo wọnyi.
40 Si kiyesi i, ki iwọ ki o ṣe wọn gẹgẹ
bi apẹrẹ wọn, ti a fihàn ọ lori oke.

## ORI 26.

IWỌ o fi aṣọ-tita mẹwa ṣe agọ́ na ; aṣọ
ọ̀gbọ olokùn wiwẹ, ati ti aṣọ-alaró, ati
ti elesè-àluko, ati ti ododó, ti on ti awọn
kerubu iṣẹ ọlọnà ni ki iwọ ki o ṣe wọn.
2 Ina aṣọ-tita kan ki o jẹ́ igbọnwọ
mejidilọgbọ̀n, ibò aṣọ-tita kan igbọnwọ
mẹrin : gbogbo aṣọ-tita na ni ki o jẹ́ ìwọn
kanna.
3 Aṣọ-tita marun ni ki a solù mọ́ ara
wọn ; ati aṣọ-tita marun keji ni ki a solù mọ́
ara wọn.
4 Iwọ o si ṣe ojóbo aṣọ-alaró si eti aṣọ-
tita kan lati iṣeti rẹ̀ wá ni ibi isolù, ati bẽ
gẹgẹ ni iwọ o ṣe li eti ikangun aṣọ-tita keji,
ni ibi isolù keji.
5 Ādọta ojóbo ni ki iwọ ki o ṣe si aṣọ-
tita kan, ãdọta ojóbo ni ki iwọ ki o si ṣe si
eti aṣọ-tita ti o wà ni isolù keji ; ki ojóbo
ki o le kọ́ ara wọn.
6 Iwọ o si ṣe ãdọta ikọ́ wurà, iwọ o si fi
ikọ́ na fà awọn aṣọ-tita so : on o si jẹ́ agọ́
kan.
7 Iwọ o si ṣe aṣọ-tita irun ewurẹ, lati ṣe
ibori sori agọ́ na : aṣọ-tita mọkanla ni iwọ
o ṣe e.
8 Ina aṣọ-tita kan yio jẹ́ ọgbọ̀n igbọnwọ,
ati ibò aṣọ-tita kan yio jẹ́ igbọnwọ mẹrin :
aṣọ-tita mọkọkanla na yio si jẹ́ ìwọn kanna.
9 Iwọ o si so aṣọ-tita marun lù mọ́ ara
wọn li ọ̀tọ, ati aṣọ-tita mẹfa lù mọ́ ara wọn
li ọ̀tọ, iwọ o si ṣẹ aṣọ-tita kẹfa po ni meji
niwaju agọ́ na.
10 Iwọ o si ṣe ãdọta ojóbo li eti aṣọ-tita
na, ti o yọ si ode jù ninu isolù, ati ãdọta
ojóbo li eti aṣọ-tita ti o so ekeji lù.
11 Iwọ o si ṣe ãdọta ikọ́ idẹ, ki o si fi ikọ́
wọnni sinu ojóbo, ki o si fi so agọ́ na pọ̀, yio
si jẹ́ ọkan.
12 Ati iyokù ti o kù ninu aṣọ-tita agọ́ na,
àbọ aṣọ-tita ti o kù, yio rọ̀ sori ẹhin agọ na.
13 Ati igbọnwọ kan li apa kan, ati igbọn-
wọ kan li apa keji, eyiti o kù ni ìna aṣọ-

Digitized by Google

tita agọ́ na, yio si rọ̀ si ìha agọ́ na ni ìha ihin ati ni ìha ọhún, lati bò o.

14 Iwọ o si ṣe ibori awọ àgbo ti a sè ni pupa fun agọ́ na, ati ibori awọ scali lori rẹ̀.

15 Iwọ o si ṣe apáko igi ṣittimu fun agọ́ na li ogurodo.

16 Igbọnwọ mẹwa ni gigùn apáko na, ati igbọnwọ kan on àbọ ni ibò apáko kan.

17 Ìtẹbọ meji ni ki o wà li apáko kan, ti o tò li ẹsẹ-ẹsẹ̀ si ara wọn: bayi ni ki iwọ ki o ṣe si gbogbo apáko agọ́ na.

18 Iwọ o si ṣe apáko agọ́ na, ogún apáko ni ìha gusù si ìha gusù.

19 Iwọ o si ṣe ogoji ihò-ìtẹbọ fadakà nisalẹ ogún apáko wọnni; ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko kan fun ìtẹbọ meji na, ati ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko keji fun ìtẹbọ meji na;

20 Ati ìha keji agọ́ na ni ìha ariwa, ogún apáko ni yio wà nibẹ̀:

21 Ati ogoji ihò-ìtẹbọ fadakà wọn; ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko na kan, ati ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko keji.

22 Ati fun ìha agọ́ na ni ìha ìwọ-õrùn apáko mẹfa ni ki-iwọ ki o ṣe.

23 Ati apáko meji ni iwọ o ṣe fun igun agọ́ na ni ìha ẹhin rẹ̀.

24 A o si so wọn pọ̀ nisalẹ, a o si so wọn pọ̀ li oke ori rẹ̀ si oruka kan: bẹ̃ni yio si ṣe ti awọn mejeji; nwọn o si ṣe ti igun mejeji.

25 Nwọn o si jẹ́ apáko mẹjọ, ati ihò-ìtẹbọ fadakà wọn, ihò-ìtẹbọ mẹrindilogun; ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko kan, ati ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko keji.

26 Iwọ o si ṣe ọpá idabu igi ṣittimu; marun fun apáko ìha kan agọ́ na,

27 Ati ọpá idabu marun fun apáko na ni ìha keji agọ́ na, ati ọpá idabu marun fun apáko na ni ìha agọ́ na, fun ìha mejeji ni ìha ìwọ-õrùn.

28 Ati ọpá ãrin li agbedemeji apáko wọnni yio ti ìku dé ìku.

29 Iwọ o si fi wurà bò apáko wọnni, iwọ o si fi wurà ṣe oruka wọn li àye fun ọpá idabu wọnni: iwọ o si fi wurà bò ọpá idabu wọnni.

30 Iwọ o si gbé agọ́ na ró, gẹgẹ bi apẹrẹ rẹ̀, ti a fihàn ọ lori oke.

31 Iwọ o si ṣe aṣọ-ikele alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ olokùn wiwẹ ti iṣẹ ọlọnà: ti on ti awọn kerubu ni ki a ṣe e:

32 Iwọ o si fi rọ̀ sara opó igi ṣittimu mẹrin, ti a fi wurà bò, wurà ni ikọ́ wọn lori ihò-ìtẹbọ fadakà mẹrẹrin na.

33 Iwọ o si ta aṣọ-ikele na si abẹ ikọ́ wọnni, ki iwọ ki o le mú apoti erí nì wá si inu aṣọ-ikele nì: aṣọ-ikele nì ni yio si pinya lãrin ibi mimọ́ ati ibi mimọ́ julọ fun nyin.

34 Iwọ o si fi itẹ́-ãnu sori apoti ẹrí nì, ni ibi mimọ́ julọ.

35 Iwọ o si gbé tabili na kà ẹhin ode aṣọ-ikele nì, ati ọpá-fitila nì kọjusi tabili na ni ìha agọ́ na ni ìha gusù: iwọ o si gbé tabili na kà ìha ariwa.

36 Iwọ ọ si ṣe aṣọ-tita kan fun ẹnu-ọ̀na agọ́ na, ti aṣọ-alaró, ti elesè-aluko, ti ododó, ati ti ọ̀gbọ olokùn wiwẹ, ti a fi iṣẹ abẹ́rẹ ṣe.

37 Iwọ o si ṣe opó igi ṣittimu marun fun aṣọ-tita na, ki o si fi wurà bò wọn; ati ikọ́ wọn wurà: iwọ o si dà ihò-ìtẹbọ idẹ marun fun wọn.

## ORI 27.

IWỌ o si tẹ́ pẹpẹ igi ṣittimu kan, ìna rẹ̀ igbọnwọ marun, ati ibò rẹ̀ igbọnwọ marun; ìwọn kan ni ìha mẹrẹrin: igbọnwọ mẹta si ni giga rẹ̀.

2 Iwọ o si ṣe iwo rẹ̀ si ori igun mẹrẹrin rẹ̀: iwo rẹ̀ yio si wà lara rẹ̀: iwọ o si fi idẹ bò o.

3 Iwọ o si ṣe tasà rẹ̀ lati ma gbà ẽru rẹ̀, ati ọkọ́ rẹ̀, ati awokòtò rẹ̀, ati kọkọrọ ẹran rẹ̀, ati awo-iná rẹ̀ wọnni: gbogbo ohun-èlo rẹ̀ ni iwọ o fi idẹ ṣe.

4 Iwọ o si ṣe oju-àro idẹ fun u ni iṣẹ-àwọn; lara àwọn na ni ki iwọ ki o ṣe oruka mẹrin ni igun mẹrẹrin rẹ̀.

5 Iwọ o si fi si abẹ ayiká pẹpẹ na nisalẹ, ki àwọn na ki o le dé idaji pẹpẹ na.

6 Iwọ o si ṣe ọpá fun pẹpẹ na, ọpá igi ṣittimu, iwọ o si fi idẹ bò wọn.

7 A o si fi ọpá rẹ̀ bọ̀ oruka wọnni, ọpá wọnni yio si wà ni ìha mejeji pẹpẹ na, lati ma fi rù u.

8 Onihò ninu ni iwọ o fi apáko ṣe e: bi a ti fihàn ọ lori oke, bẹ̃ni ki nwọn ki o ṣe e.

9 Iwọ o si ṣe agbalá agọ́ na: ni ìha gusù lọwọ ọtún li aṣọ-tita agbalá ti ọ̀gbọ olokùn wiwẹ ti ọgọrun igbọnwọ ìna, yio wà ni ìha kan:

10 Ati ogún opó rẹ̀, ati ogún ihò-ìtẹbọ wọn, ki o jẹ́ idẹ; ikọ́ opó wọnni ati ọpá isopọ̀ wọn ki o jẹ́ fadakà.

11 Ati bẹ̃ gẹgẹ niti ìha ariwa ni gigùn aṣọ-tita wọnni yio jẹ́ ọgọrun igbọnwọ ni ìna wọn, ati ogún opó rẹ̀, ati ogún ihò-ìtẹbọ rẹ̀ ki o jẹ́ idẹ; ikọ́ opó wọnni ati ọpá isopọ̀ wọn ki o jẹ́ fadakà.

12 Ati niti ibú agbalá na, ni ìha ìwọ-õrùn li aṣọ-tita ãdọta igbọnwọ yio wà: opó wọn mẹwa, ati ihò-ìtẹbọ wọn mẹwa.

13 Ati ibú agbalá na ni ìha ìla-õrùn si ìha ìla-õrùn yio jẹ́ ãdọta igbọnwọ.



Digitized by Google

14 Aṣọ-tita apakan ẹnu-ọ̀na na yio jẹ́ igbọnwọ mẹdogun: opó wọn mẹta, ihò-ìtẹ̀bọ wọn mẹta.
15 Ati ni ìha keji ni aṣọ-tita igbọ̄nwọ mẹdogun yio wà: opó wọn mẹta, ati ihò-ìtẹbọ wọn mẹta.
16 Ati fun ẹnu-ọ̀na agbalá na aṣọ-tita ogún igbọnwọ yio wà, ti aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ti ọ̀gbọ olokùn wiwẹ, ti a fi iṣẹ abẹ́rẹ ṣe: opó wọn mẹrin, ati ihò-ìtẹbọ wọn mẹrin.
17 Gbogbo opó ti o yi sarè na ká li a o si fi ọpá fadakà sopọ̀; ikọ́ wọn yio jẹ́ fadakà, ati ihò-ìtẹbọ wọn ti idẹ.
18 Ìna agbalá na ki o jẹ́ ọgọrun igbọnwọ, ati ibú rẹ̀ arādọtọta igbọnwọ, ati giga rẹ̀ igbọnwọ marun, ti ọ̀gbọ olokùn wiwẹ, ati ihò-ìtẹbọ wọn ti idẹ.
19 Gbogbo ohun-èlo agọ́ na, ni gbogbo ìsin rẹ̀, ati gbogbo ekàn rẹ̀, ati gbogbo ekàn agbalá na ki o jẹ́ idẹ.
20 Iwọ o si paṣẹ fun awọn ọmọ Israeli, ki nwọn ki o mú oróro olifi daradara ti a gún fun ọ wá, fun imọlẹ, lati mu ki fitila ki o ma tàn nigbagbogbo.
21 Li agọ́ ajọ lẹhin ode aṣọ-ikele ti o wà niwaju ẹrí na, Aaroni ti on ti awọn ọmọ rẹ̀ ni yio tọju rẹ̀ lati alẹ titi di owurọ̀ niwaju OLUWA: yio si di ìlana lailai ni irandiran wọn lọdọ awọn ọmọ Israeli.

ORI 28.

IWỌ si mú Aaroni arakọnrin rẹ, ati awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀ si ọdọ rẹ, kuro ninu awọn ọmọ Israeli, ki on ki o le ma ṣe iṣẹ alufa fun mi, ani Aaroni, Nadabu ati Abihu, Eleasari ati Itamari, awọn ọmọ Aaroni.
2 Iwọ o si dá aṣọ mimọ́ fun Aaroni arakọnrin rẹ fun ogo ati fun ọṣọ́.
3 Iwọ o si sọ fun gbogbo awọn ti o ṣe amoye, awọn ẹniti mo fi ẹmi ọgbọ́n kún, ki nwọn ki o le dá aṣọ Aaroni lati yà a simimọ́, ki o le ma ṣe iṣẹ alufa fun mi.
4 Wọnyi si li aṣọ ti nwọn o dá; igbàiya kan, ati ẹ̀wu-efodi, ati aṣọ igunwà, ati ẹ̀wu-awọtẹlẹ ọlọnà, fila, ati ọjá-amure: nwọn o si dá aṣọ mimọ́ wọnyi fun Aaroni arakọnrin rẹ, ati fun awọn ọmọ rẹ̀, ki on ki o le ma ṣe iṣẹ alufa fun mi.
5 Nwọn o si mú wurà, ati aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ.
6 Nwọn o si ṣe ẹ̀wu-efodi ti wurà, ti aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ti ododó, ati ọ̀gbọ olokùn wiwẹ iṣẹ ọlọnà,
7 Yio ní aṣọ ejika meji ti o solù li eti rẹ̀ mejeji; bẹ̄ni ki a so o pọ̀.
8 Ati onirūru-ọnà ọjá rẹ̀, ti o wà lori rẹ̀ yio ri bakanna, gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀; ti wurà, ti aṣọ-alaró, ododó, ati ọ̀gbọ olokùn wiwẹ.
9 Iwọ o si mú okuta oniki meji, iwọ o si fin orukọ awọn ọmọ Israeli sara wọn:
10 Orukọ awọn mẹfa sara okuta kan, ati orukọ mẹfa iyokù sara okuta keji, gẹgẹ bi ibí wọn.
11 Iṣẹ-ọnà afin-okuta, bi ifin èdidi-àmi, ni iwọ o fin okuta mejeji gẹgẹ bi orukọ awọn ọmọ Israeli: iwọ o si dè wọn si oju-ìde wurà.
12 Iwọ o si fi okuta mejeji si ejika ẹ̀wu-efodu na, li okuta iranti fun awọn ọmọ Israeli; Aaroni yio si ma rù orukọ wọn niwaju OLUWA li ejika rẹ̀ mejeji fun iranti.
13 Iwọ o si ṣe oju-ìde wurà:
14 Ati okùn ẹ̀wọn meji ti kìki wurà; iṣẹ ọnà-lilọ ni ki iwọ ki o fi ṣe wọn, ki iwọ ki o si so okùn ẹ̀wọn iṣẹ ọnà-lilọ nì si oju-ìde na.
15 Iwọ o si fi iṣẹ ọgbọ́n na ṣe igbàiya idajọ na; nipa iṣẹ-ọnà ẹ̀wu-efodi ni iwọ o ṣe e; ti wurà, ti aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ olokùn wiwẹ ni iwọ o fi ṣe e.
16 Iha mẹrin ọgbọgba ni ki iwọ ki o ṣe e ni iṣẹpo meji; ika kan ni ìna rẹ̀, ika kan si ni ibú rẹ̀.
17 Iwọ o si tò ìto okuta sinu rẹ̀, ẹsẹ̀ okuta mẹrin: ẹsẹ̀ kini, sardiu, topasi, ati smaragdu; eyi li ẹsẹ̀ kini:
18 Ẹsẹ̀ keji, emeraldi, safiru, ati diamondi;
19 Ati ẹsẹ̀ kẹta, ligure, agate, ati ametistu;
20 Ati ẹsẹ̀ kẹrin, berilu, ati oniki, ati jasperi: a o si tò wọn si oju wurà ni didè wọn.
21 Okuta wọnni yio si wà gẹgẹ bi orukọ awọn ọmọ Israeli mejila, gẹgẹ bi orukọ wọn; bi ifin edidi-àmi; olukuluku gẹgẹ bi orukọ rẹ̀ ni nwọn o wà fun ẹ̀ya Israeli mejejila.
22 Iwọ o si ṣe okùn ẹ̀wọn kìka wurà, iṣẹ ọnà-lilọ si igbàiya na.
23 Iwọ o si ṣe oruka wurà meji sara igbàiya na, iwọ o si fi oruka meji na si eti mejeji igbàiya na.
24 Iwọ o si fi okùn ẹ̀wọn wurà mejeji sinu oruka meji wọnni li eti igbàiya na.
25 Ati eti ẹ̀wọn meji ni ki iwọ ki o so mọ́ oju-ìde mejeji, ki o si fi si ejika ẹ̀wu-efodi na niwaju rẹ̀.
26 Iwọ o si ṣe oruka wurà meji, iwọ o si fi wọn si eti mejeji igbàiya na li eti rẹ̀, ti o wà ni ìha ẹ̀wu-efodi na ni ìha inu.

Digitized by Google

27 Iwọ o si ṣe oruka wurà meji, iwọ o si fi wọn si ejika ẹ̀wu-efodi mejeji nisalẹ, si ìha iwaju rẹ̀, ti o kọjusi isolù rẹ̀, loke onirũru-ọnà ọjá ẹ̀wu-efodi na.

28 Nwọn o si fi oruka rẹ̀ so igbàiya na mọ́ oruka ẹ̀wu-efodi na ti on ti ọjá àwọn alaró, ki o le wà loke onirũru-ọnà ọjá ẹ̀wu-efodi na, ki a má si ṣe tú igbàiya na kuro lara ẹ̀wu-efodi na.

29 Aaroni yio si ma rù orukọ awọn ọmọ Israeli ninu igbàiya idajọ li àiya rẹ̀, nigbati o ba nwọ̀ ibi mimọ́ nì lọ, fun iranti nigbagbogbo niwaju OLUWA.

30 Iwọ o si fi Urimu on Tummimu sinu igbàiya idajọ; nwọn o si wà li àiya Aaroni, nigbati o ba nwọle lọ niwaju OLUWA; Aaroni yio si ma rù idajọ awọn ọmọ Israeli li àiya rẹ̀ nigbagbogbo niwaju OLUWA.

31 Iwọ o si ṣe aṣọ igunwa ẹ̀wu-efodi na ni kìki aṣọ-alaró.

32 Oju ọrùn yio si wà lãrin rẹ̀ fun ori; ọjá iṣẹti yio si wà yi oju rẹ̀ ká, iṣẹ-oniṣọnà gẹgẹ bi ẹ̀wu ogun, ki o má ba fàya.

33 Ati ni iṣẹti rẹ̀ nisalẹ ni iwọ o ṣe pomegranate aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, yi iṣẹti rẹ̀ ká; ati ṣaworo wurà lãrin wọn yiká;

34 Ṣaworo wurà kan ati pomegranate kan, ṣaworo wurà kan ati pomegranate kan, li eti iṣẹti aṣọ igunwa na yiká.

35 On o si wà lara Aaroni lati ma fi ṣiṣẹ: a o si ma gbọ́ iró rẹ̀ nigbati o ba wọ̀ ibi mimọ́ lọ niwaju OLUWA, ati nigbati o ba si njade bọ̀, ki o má ba kú.

36 Iwọ o si ṣe awo ni kìki wurà, iwọ o si fin sara rẹ̀, gẹgẹ bi fifin èdidi-àmi pe, MIMỌ́ SI OLUWA.

37 Iwọ o si fi i sara ọjá-àwọn alaró, ki o le ma wà lara fila nì, niwaju fila na ni ki o wà.

38 On o si ma wà niwaju ori Aaroni, ki Aaroni le ma rù ẹ̀ṣẹ ohun mimọ́, ti awọn ọmọ Israeli yio si yàsimimọ́, ninu gbogbo ẹ̀bun mimọ́ wọn: on o si ma wà niwaju ori rẹ̀ nigbagbogbo, ki OLUWA ki o le ní inudidùn si wọn.

39 Iwọ o si fi ọ̀gbọ didara wun ẹ̀wu-awọtẹlẹ, iwọ o si fi ọ̀gbọ didara ṣe fila, iwọ o si fi iṣẹ abẹ́rẹ ṣe ọjá-amure.

40 Iwọ o si dá ẹ̀wu-awọtẹlẹ fun awọn ọmọ Aaroni, iwọ o si dá ọjá-amure fun wọn, iwọ o si dá fila fun wọn, fun ogo ati fun ọṣọ́.

41 Iwọ o si fi wọn wọ̀ Aaroni arakọnrin rẹ, ati awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀; iwọ o si ta oróro si wọn li ori, iwọ o si yà wọn simimọ́, iwọ o si sọ wọn di mimọ́, ki nwọn ki o le ma ṣe iṣẹ alufa fun mi.

42 Iwọ o si dá ṣòkoto ọ̀gbọ fun wọn lati ma fi bò ìhoho wọn, ki o ti ibadi dé itan:

43 Nwọn o si wà lara Aaroni, ati lara awọn ọmọ rẹ̀, nigbati nwọn ba wọ̀ inu agọ́ ajọ lọ, tabi nigbati nwọn ba sunmọ pẹpẹ, lati ṣiṣẹ ni ibi mimọ́; ki nwọn ki o má ba dẹ̀ṣẹ, nwọn a si kú: ìlana lailai ni fun u ati fun irú-ọmọ rẹ̀ lẹhin rẹ̀.

## ORI 29.

EYI si li ohun ti iwọ o ṣe si wọn lati yà wọn simimọ́, lati ma ṣe alufa fun mi: mú ẹgbọ̀rọ akọmalu kan, ati àgbo meji ti kò li abùkun.

2 Ati àkara alaiwu, ati adidùn àkara alaiwu ti a fi oróro pò, ati àkara fẹlẹfẹlẹ alaiwu ti a ta oróro si lori; iyẹfun alikama ni ki o fi ṣe wọn.

3 Iwọ o si fi wọn sinu agbọ̀n kan, iwọ o si mú wọn wá ninu agbọ̀n na, pẹlu akọmalu na ati àgbo mejeji.

4 Iwọ o si mú Aaroni pẹlu awọn ọmọ rẹ̀ wá si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, iwọ o si fi omi wẹ̀ wọn.

5 Iwọ o si mú aṣọ wọnni, iwọ o si fi ẹ̀wu-awọtẹlẹ nì wọ̀ Aaroni, ati aṣọ igunwa efodi, ati efodi, ati igbàiya, ki o si fi onirũru-ọnà ọjá ẹ̀wu-efodi dì i.

6 Iwọ o si fi fila nì dé e li ori, iwọ o si fi adé mimọ́ nì sara fila na.

7 Nigbana ni iwọ o si mú oróro itasori, iwọ o si dà a si i li ori, iwọ o si fi oróro yà a simimọ́.

8 Iwọ o si mú awọn ọmọ rẹ̀ wá tosi, iwọ o si wọ̀ wọn li ẹ̀wu.

9 Iwọ o si dì wọn li ọjá-amure, Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀, iwọ o si fi fila dé wọn: iṣẹ-alufa yio si ma jẹ́ ti wọn ni ìlana titi aiye: iwọ o si yà Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ simimọ́.

10 Iwọ o si mú akọmalu na wá siwaju agọ́ ajọ: ati Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ yio si fi ọwọ́ wọn lé akọmalu na li ori.

11 Iwọ o si pa akọmalu na niwaju OLUWA, loju ọ̀na agọ́ ajọ.

12 Iwọ o si mú ninu ẹ̀jẹ akọmalu na, iwọ o si fi ika rẹ tọ́ ọ sara iwo pẹpẹ na; iwọ o si dà gbogbo ẹ̀jẹ na si ìha isalẹ pẹpẹ na.

13 Iwọ o si mú gbogbo ọrá ti o bò ifun lori, ati àwọn ti o bori ẹ̀dọ, ati ti iwe mejeji, ati ọrá ti o wà lara wọn, iwọ o si sun u lori pẹpẹ na.

14 Ṣugbọn ẹran akọmalu na, ati awọ rẹ̀,

Digitized by Google

ati igbẹ rẹ̀, on ni ki iwọ ki o fi iná sun lẹ-
hin ode ibudó: ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni.
15 Iwọ o si mú àgbo kan; ati Aaroni
ati awọn ọmọ rẹ̀ yio si fi ọwọ́ wọn lé àgbo
na li ori.
16 Iwọ o si pa àgbo na, iwọ o si mú ẹ̀jẹ
rẹ̀, iwọ o si fi i wọ́n pẹpẹ na yiká.
17 Iwọ o si kun àgbo na, iwọ o si fọ̀ ifun
rẹ̀, ati itan rẹ̀, iwọ o si fi wọn lé ara wọn,
ati lé ori rẹ̀.
18 Iwọ o si sun gbogbo àgbo na lori pẹ-
pẹ na: ẹbọ sisun ni si OLUWA: õrùn di-
dùn ni, ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA.
19 Iwọ o si mú àgbo keji; Aaroni ati
awọn ọmọ rẹ̀ yio si fi ọwọ́ wọn lé àgbo na li
ori.
20 Nigbana ni ki iwọ ki o pa àgbo na,
ki o si mú ninu ẹ̀jẹ rẹ̀, ki o si tọ́ ọ si eti
ọtún Aaroni, ati si eti ọtún awọn ọmọ rẹ̀,
ati si àtampako ọwọ́ ọtún wọn, ati si àtam-
pako ẹsẹ̀ ọtún wọn, ki o si fi ẹ̀jẹ na wọ́n
pẹpẹ na yiká.
21 Iwọ o si mú ninu ẹ̀jẹ ti o wà lori pẹ-
pẹ, ati ninu oróro itasori, iwọ o si wọ́n ọ
sara Aaroni, ati sara aṣọ rẹ̀, ati sara awọn
ọmọ rẹ̀, ati sara aṣọ awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu
rẹ̀: ki a le sọ ọ di mimọ́, ati aṣọ rẹ̀, ati
awọn ọmọ rẹ̀, ati aṣọ awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀.
22 Iwọ o si mú ọrá, ati ìru ti o lọrá ti
àgbo na, ati ọrá ti o bò ifun lori, ati àwọn
ti o bò ẹ̀dọ̀, ati iwe mejeji, ati ọrá ti o wà
lara wọn, ati itan ọtún; nitori àgbo ìyasi-
mimọ́ ni:
23 Ati ìṣu àkara kan, ati àkara kan ti a
fi oróro din, ati àkara fẹlẹfẹlẹ kan kuro ni-
nu agbọ̀n àkara alaiwu, ti o wà niwaju
OLUWA:
24 Iwọ o si fi gbogbo rẹ̀ lé Aaroni lọwọ,
ati lé ọwọ́ awọn ọmọ rẹ̀; iwọ o si ma fì
wọn li ẹbọ fifì niwaju OLUWA.
25 Iwọ o si gbà wọn li ọwọ́ wọn, iwọ o
si sun wọn lori pẹpẹ na li ẹbọ sisun, fun
õrùn didùn niwaju OLUWA: ẹbọ ti a fi iná
ṣe ni si OLUWA.
26 Iwọ o si mú igẹ̀ àgbo ìyasimimọ́ Aa-
roni, iwọ o si fì i li ẹbọ fifì niwaju OLU-
WA; ipín tirẹ li eyinì.
27 Iwọ o si yà igẹ̀ ẹbọ fifì na simimọ́, ati
itan ẹbọ agbesọsoke, ti a fì ti a si gbesọso-
ke ninu àgbo ìyasimimọ́ na, ani ninu eyiti
iṣe ti Aaroni, ati ninu eyiti iṣe ti awọn
ọmọ rẹ̀:
28 Eyi ni yio si ma ṣe ti Aaroni ati ti
awọn ọmọ rẹ̀ ni ìlana lailai lọwọ awọn ọmọ
Israeli: nitori ẹbọ agbesọsoke ni: ẹbọ
agbesọsoke ni yio si ṣe lati ọwọ́ awọn ọmọ
Israeli, ninu ẹbọ alafia wọn, ani ẹbọ agbe-
sọsoke wọn si OLUWA.
29 Ati aṣọ mimọ́ ti Aaroni ni yio ṣe ti
awọn ọmọ rẹ̀ lẹhin rẹ̀, lati ma fi oróro yàn
wọn ninu wọn, ati lati ma yà wọn simimọ́
ninu wọn.
30 Ẹnikan ninu awọn ọmọ rẹ̀ ti o ba jẹ́
alufa ni ipò rẹ̀ ni yio mú wọn wọ̀ ni ijọ́ me-
je, nigbati o ba wá sinu agọ́ ajọ, lati ṣe ìsin
ni ibi mimọ́ nì.
31 Iwọ o si mú àgbo ìyasimimọ́ nì, iwọ o
si bọ̀ ẹran rẹ̀ ni ibi mimọ́ kan.
32 Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ yio si jẹ ẹran
àgbo na, ati àkara na ti o wà ninu agbọ̀n
nì, li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ.
33 Nwọn o si jẹ nkan wọnni ti a fi ṣètu-
tu na, lati yà wọn simimọ́, ati lati sọ wọn
di mimọ́: ṣugbọn alejò ni kò gbọdọ jẹ ninu
rẹ̀, nitoripe mimọ́ ni.
34 Bi ohun kan ninu ẹran ìyasimimọ́ na,
tabi ninu àkara na, ba kù titi di ojumọ́,
nigbana ni ki iwọ ki o fi iná sun iyokù: a
ki yio jẹ ẹ, nitoripe mimọ́ ni.
35 Bayi ni iwọ o si ṣe fun Aaroni, ati fun
awọn ọmọ rẹ̀, gẹgẹ bi ohun gbogbo ti mo
paṣẹ fun ọ: ijọ́ meje ni iwọ o fi yà wọn si-
mimọ́.
36 Iwọ o si ma pa akọmalu kọkan li
ojojumọ́ ṣe ẹbọ ẹ̀ṣẹ fun ètutu: iwọ o si wẹ̀
pẹpẹ na mọ́, nigbati iwọ ba ṣètutu si i tán,
iwọ o si ta oróro si i lati yà a simimọ́.
37 Ni ijọ́ meje ni iwọ o fi ṣètutu si pẹpẹ
na, iwọ o si yà a simimọ́: on o si ṣe pẹpẹ
mimọ́ julọ; ohunkohun ti o ba fọwọkàn
pẹpẹ na, mimọ́ ni yio jẹ́.
38 Njẹ eyi ni iwọ o ma fi rubọ lori pẹpẹ
na; ọdọ-agutan meji ọlọdún kan li ojojumọ́
lailai.
39 Ọdọ-agutan kan ni iwọ o fi rubọ li
owurọ̀; ati ọdọ-agutan keji ni iwọ o fi rubọ
li aṣalẹ:
40 Ati idamẹwa òṣuwọn iyẹfun ti a fi
idamẹrin hini oróro ti a gún pòlu; ati ida-
mẹrin òṣuwọn hini ọti-waini fun ẹbọ mimu,
fun ọdọ-agutan ekini.
41 Ọdọ-agutan keji ni ki iwọ ki o pa ru-
bọ li aṣalẹ, iwọ o si ṣe si i gẹgẹ bi ẹbọ jijẹ
owurọ̀, ati gẹgẹ bi ẹbọ mimu rẹ̀, fun õrùn
didùn, ẹbọ ti a fi iná ṣe ni si OLUWA.
42 Ẹbọ sisun titilai ni yio ṣe lati ìran-
diran nyin li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ niwaju OLU-
WA: nibiti emi o ma bá nyin pade lati ma
bá ọ sọ̀rọ nibẹ̀.
43 Nibẹ̀ li emi o ma pade awọn ọmọ
Israeli; a o si fi ogo mi yà agọ́ na simimọ́.
44 Emi o si yà agọ́ ajọ na simimọ́, ati

Digitized by Google

pẹpẹ nì: emi o si yà Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ simimọ́, lati ma sẹ iṣẹ alufa fun mi.

45 Emi o si ma gbé ãrin awọn ọmọ Israeli, emi o si ma ṣe Ọlọrun wọn.

46 Nwọn o si mọ̀ pe emi li OLUWA Ọlọrun wọn, ti o mú wọn lati ilẹ Egipti jade wá, ki emi ki o le ma gbé ãrin wọn: emi li OLUWA Ọlọrun wọn.

## ORI 30.

IWỌ o si ṣe pẹpẹ kan lati ma jó turari lori rẹ̀: igi ṣittimu ni ki iwọ ki o fi ṣe e.

2 Igbọnwọ kan ni gigùn rẹ̀, ati igbọnwọ kan ni ibú rẹ̀; ìha mẹrin ọgbọgba ni ki o jẹ́: igbọnwọ meji si ni giga rẹ̀: iwo rẹ̀ yio si wà lara rẹ̀.

3 Iwọ o si fi kìki wurà bò o, oke rẹ̀, ati ìha rẹ̀ yiká, ati iwo rẹ̀; iwọ o si ṣe igbáti wurà yi i ká.

4 Ati oruka wurà meji ni ki iwọ ki o ṣe nisalẹ igbáti rẹ̀, ni ìha igun rẹ̀ meji, li ẹgbẹ rẹ̀ mejeji ni ki iwọ ki o ṣe e si; nwọn o si jasi ipò fun ọpá wọnni, lati ma fi gbé e.

5 Iwọ o si fi igi ṣittimu ṣe ọpá wọnni, iwọ o si fi wurà bò wọn.

6 Iwọ o si gbé e kà iwaju aṣọ-ikele nì ti o wà lẹba apoti ẹrí, niwaju itẹ́-ãnu ti o wà lori apoti ẹrí nì, nibiti emi o ma bá ọ pade.

7 Aaroni yio si ma jó turari didùn lori rẹ̀; li orowurọ̀, nigbati o ba tun fitila wọnni ṣe, on o si ma jó o lori rẹ̀.

8 Nigbati Aaroni ba si tàn fitila wọnni li aṣalẹ, yio si ma jó turari lori rẹ̀, turari titilai niwaju OLUWA lati irandiran nyin.

9 Ẹnyin kò gbọdọ mú ajeji turari wá sori rẹ̀, tabi ẹbọ sisun, tabi ẹbọ onjẹ: bẹ̃li ẹnyin kò gbọdọ dà ẹbọ ohun mimu sori rẹ̀.

10 Aaroni yio si ma fi ẹ̀jẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ ètutu ṣètutu lori iwo rẹ̀ lẹ̃kan li ọdún: yio ṣètutu lori rẹ̀ lẹ̃kan li ọdun lati irandiran nyin: mimọ́ julọ ni si OLUWA.

11 OLUWA si sọ fun Mose pe,

12 Nigbati iwọ ba kà iye awọn ọmọ Israeli, gẹgẹ bi ẹgbẹ wọn, nigbana li olukuluku ọkọnrin yio mú irapada ọkàn rẹ̀ fun OLUWA wá, nigbati iwọ ba kà iye wọn; ki ajakalẹ-àrun ki o máṣe sí ninu wọn, nigbati iwọ ba nkà iye wọn.

13 Eyi ni nwọn o múwa, olukuluku ẹniti o ba kọja sinu awọn ti a kà, àbọ ṣekeli, ani ṣekeli ibi mimọ́: (ogún gera ni ṣekeli kan:) àbọ ṣekeli li ọrẹ fun OLUWA.

14 Olukuluku ẹniti o ba kọja sinu awọn ti a kà, lati ẹni ogún ọdún ati jù bẹ̃ lọ, ni yio fi ọre fun OLUWA.

15 Olowo ki o san jù bẹ̃ lọ, bẹ̃li awọn talaka kò si gbọdọ dí li àbọ ṣekeli, nigbati nwọn ba mú ọrẹ wá fun OLUWA lati ṣètutu fun ọkàn nyin.

16 Iwọ o si gbà owo ètutu na lọwọ awọn ọmọ Israeli, iwọ o si fi i lelẹ fun ìsin agọ́ ajo; ki o le ma ṣe iranti fun awọn ọmọ Israeli niwaju OLUWA, lati ṣètutu fun ọkàn nyin.

17 OLUWA si sọ fun Mose pe,

18 Iwọ o si ṣe agbada idẹ kan, ati ẹsẹ̀ rẹ̀ idẹ, fun wiwẹ̀: iwọ o si gbé e kà agbedemeji agọ́ ajọ, ati pẹpẹ nì, iwọ o si pọn omi sinu rẹ̀.

19 Nitori Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ yio ma wẹ̀ ọwọ́ wọn ati ẹsẹ̀ wọn nibẹ̀:

20 Nigbati nwọn ba nwọ̀ inu agọ́ ajọ lọ, nwọn o fi omi wẹ̀ ki nwọn ki o má ba kú: tabi nigbati nwọn ba sunmọ pẹpẹ nì lati ṣe ìsin, lati ru ẹbọ sisun ti a fi iná ṣe si OLUWA:

21 Nwọn o si wẹ̀ ọwọ́ wọn ati ẹsẹ̀ wọn, ki nwọn ki o má ba kú: yio si di ìlana fun wọn lailai, fun u ati fun irú-ọmọ rẹ̀ lati irandiran wọn.

22 OLUWA si sọ fun Mose pe,

23 Iwọ mú ãyo olõrùn si ọdọ rẹ, pẹlu ojia ṣiṣàn ẹdẹgbẹta ṣekeli, ati kinnamoni didùn idameji bẹ̃, ani ãdọtale-rugba ṣekeli, ati kalamu didùn ãdọtale-rugba ṣekeli,

24 Ati kassia ẹdẹgbẹta ṣekeli, ṣekeli ibi mimọ́, ati hini oróro olifi kan:

25 Iwọ o si ṣe e li oróro mimọ́ ikunra, ti a fi ọgbọ́n alapòlu pò: yio si jẹ́ oróro mimọ́ itasori.

26 Iwọ o si ta ninu rẹ̀ sara agọ́ ajọ, ati apoti ẹrí nì,

27 Ati tabili ati ohunèlo rẹ̀ gbogbo, ati ọpáfitila ati ohun-èlo rẹ̀, ati pẹpẹ turari,

28 Ati pẹpẹ ẹbọ sisun pẹlu gbogbo ohunèlo rẹ̀, ati agbada ati ẹsẹ̀ rẹ̀.

29 Iwọ o si yà wọn simimọ́, ki nwọn ki o le ṣe mimọ́ julọ: okunkohun ti o ba fọwọkàn wọn yio di mimọ́.

30 Iwọ o si torórosi Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀, iwọ o si yà wọn simimó, ki nwon ki o le ma ṣe alufa fun mi.

31 Iwọ o si sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Eyi ni yio ma ṣe oróro mimọ́ itasori fun mi lati irandiran nyin.

32 A ko gbọdọ dà a si ara enia, bẹ̃li ẹnyin kò gbọdọ ṣe irú rẹ̀, ni ìwọn pipò rẹ̀: mimọ́ ni, yio si ma ṣe mimọ́ fun nyin.

33 Ẹnikẹni ti o ba pò bi irú rẹ̀, tabi ẹni kẹni ti o ba fi sara alejò ninu rẹ̀, on li a o si ke kuro ninu awọn enia rẹ̀.

34 OLUWA si wi fun Mose pe, Mú olõrùn

Digitized by Google

didùn sọdọ rẹ, stakte, ati onika, ati galba-
numu ; olõrùn didùn wọnyi, pẹlu turari
daradara : òṣuwọn kan na li olukuluku ;
35 Iwọ o si ṣe e ni turari, apòlu nipa
ọgbọ́n-ọnà alapòlu, ti a fi iyọ̀ si, ti o dara ti
o si mọ́.
36 Iwọ o si gún diẹ ninu rẹ̀ kunna, iwọ
o si fi i siwaju ẹrí ninu rẹ̀ ninu agọ́ ajọ, ni-
biti emi o gbé ma bá ọ pade : yio ṣe mimọ́
julọ fun nyin.
37 Ati ti turari ti iwọ o ṣe, ẹnyin kò
gbọdọ ṣe e fun ara nyin ni ìwọn pipọ̀ rẹ̀ :
yio si ṣe mimọ́ fun ọ si OLUWA.
38 Ẹnikẹni ti o ba ṣe irú rẹ̀, lati ma gbõ-
rùn rẹ̀, on li a o ke kuro ninu awọn enia rẹ̀.

## ORI 31.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Wò o, emi ti pè Besaleli li orukọ,
ọmọ Uri, ọmọ Huri, ti ẹ̀ya Judah :
3 Emi si fi ẹmi Ọlọrun kún u li ọgbọ́n,
ati li oyé, ati ni ìmọ, ati li onirũru iṣẹ-ọnà.
4 Lati humọ̀ alarabara iṣẹ, lati ṣiṣẹ ni
wurà, ati ni fadakà, ati ni idẹ,
5 Ati li okuta gbigbẹ lati tò wọn, ati ni
igi fifin, lati ṣiṣẹ li onirũru iṣẹ-ọnà.
6 Ati emi, kiyesi i, mo fi Oholiabu, ọmọ
Ahisamaki, ti ẹ̀ya Dani, pẹlu rẹ̀ ; ati ninu
ọkàn awọn ti iṣe ọlọgbọ́n inu ni mo fi ọgbọ́n
si, ki nwọn ki o le ma ṣe ohun gbogbo ti mo
palaṣẹ fun ọ :
7 Agọ́ ajọ na, ati apoti ẹrí nì, ati itẹ́-ãnu
ti o wà lori rẹ̀, ati gbogbo ohunèlo Agọ́ na.
8 Ati tabili na ati ohun-èlo rẹ̀, ati ọpá-
fitila mimọ́ pẹlu gbogbo ohunèlo rẹ̀, ati pẹpẹ
turari ;
9 Ati pẹpẹ ẹbọ sisun pẹlu gbogbo ohun-
èlo rẹ̀, ati agbada nì ti on ti ẹsẹ̀ rẹ̀ ;
10 Ati aṣọ ìsin, ati aṣọ mimọ́ wọnni fun
Aaroni alufa, ati aṣọ awọn ọmọ rẹ̀, lati ma
fi ṣe iṣẹ alufa ;
11 Ati oróro itasori, ati turari olõrùn
didùn fun ibi mimọ́ nì : gẹgẹ bi gbogbo
eyiti mo palaṣẹ fun ọ ni nwọn o ṣe.
12 OLUWA si sọ fun Mose pe,
13 Ki iwọ ki o sọ fun awọn ọmọ Israeli
pe, Ọjọ́ isimi mi li ẹnyin o pamọ́ nitõtọ :
nitori àmi ni lãrin emi ati lãrin nyin lati
irandiran nyin ; ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe emi
li OLUWA ti o yà nyin simimọ́.
14 Nitorina ki ẹnyin ki o ma pa ọjọ́ isi-
mi mọ́ ; nitoripe mimọ́ ni fun nyin : ẹniti
o ba bà a jẹ́ on li a o pa nitõtọ : nitori ẹni-
kẹni ti o ba ṣe iṣẹkiṣẹ kan ninu rẹ̀, ọkàn na
li a o ke kuro ninu awọn enia rẹ̀.
15 Ijọ́ mẹfa ni ki a ṣe iṣẹ ; ṣugbọn ni
ọjọ́ keje ni ọjọ́ isimi, mimọ́ ni si OLUWA :
ẹnikẹni ti o ba ṣe iṣẹkiṣẹ li ọjọ́ isimi, on li
a o si pa nitõtọ.
16 Nitorina li awọn ọmọ Israeli yio ṣe
ma pa ọjọ́ isimi mọ́, lati ma kiyesi ọjọ́ isi-
mi lati irandiran wọn, fun majẹmu titilai.
17 Àmi ni iṣe lãrin emi ati lárin awọn
ọmọ Israeli titilai : nitori ni ijọ́ mẹfa li
OLUWA dá ọrun on aiye, ni ijọ́ keje o si si-
mi, o si ṣe ìtura.
18 O si fi walã ẹrí meji, walã okuta, ti a
fi ika Ọlọrun kọ, fun Mose, nigbati o pari
ọ̀rọ bibá a sọ tán lori oke Sinai.

## ORI 32.

NIGBATI awọn enia ri pe, Mose pẹ lati
sọkalẹ ti ori òke wá, awọn enia kó ara
wọn jọ sọdọ Aaroni, nwọn si wi fun u pe,
Dide, dá oriṣa fun wa, ti yio ma ṣaju wa lọ ;
bi o ṣe ti Mose yi ni, ọkọnrin nì ti o mú
wa gòke lati ilẹ Egipti wá, awa kò mọ̀
ohun ti o ṣe e.
2 Aaroni si wi fun wọn pe, Ẹ kán oruka
wurà ti o wà li eti awọn aya nyin, ati ti
awọn ọmọkọnrin nyin, ati ti awọn ọmọbirin
nyin, ki ẹ si mú wọn tọ̀ mi wá.
3 Gbogbo awọn enia si kán oruka wurà
ti o wà li eti wọn, nwọn si mú wọn tọ̀ Aa-
roni wá.
4 O si gbà wọn li ọwọ́ wọn, o si fi ohun-
ọ̀nà fifin ṣe e, nigbati o si dà a li aworan
ẹgbọrọmalu tán : nwọn si wipe, Israeli,
wọnyi li oriṣa rẹ, ti o mú ọ gòke lati ilẹ
Egipti wá.
5 Nigbati Aaroni si ri i, o tẹ́ pẹpẹ kan
niwaju rẹ̀ ; Aaroni si kede, o si wipe, Ọla
li ajọ fun OLUWA.
6 Nwọn si dide ni kùtukutu ijọ́ keji
nwọn si ru ẹbọ sisun, nwọn si mú ẹbọ alafia
wá : awọn enia si joko lati jẹ ati lati mu,
nwọn si dide lati ṣire.
7 OLUWA si sọ fun Mose pe, Lọ, sọkalẹ
lọ ; nitoriti awọn enia rẹ, ti iwọ mú gòke
lati ilẹ Egipti wá, nwọn ti ṣẹ̀.
8 Nwọn ti yipada kánkan kuro ni ipa-
ọ̀na ti mo làsilẹ fun wọn : nwọn ti dá ere
ẹgbọrọmalu fun ara wọn, nwọn si ti mbọ ọ,
nwọn si ti rubọ si i, nwọn nwipe, Israeli,
wọnyi li oriṣa rẹ, ti o mú ọ gòke lati ilẹ
Egipti wá.
9 OLUWA si wi fun Mose pe, Emi ti ri
awọn enia yi, si kiyesi i, ọlọrùn lile enia
ni :
10 Njẹ nisisiyi jọwọ mi jẹ, ki ibinu mi ki
o gbona si wọn, ki emi ki o le pa wọn run :
emi o si sọ iwọ di orilẹ-ède nla.

Digitized by Google

11 Mose si bẹ̀ OLUWA Ọlọrun rẹ̀, o si wipe, OLUWA, ẽtiṣe ti ibinu rẹ fi gbona si awọn enia rẹ, ti iwọ fi ipá nla ati ọwọ́ agbara rẹ mú lati ilẹ Egipti jade wá?

12 Nitori kini awọn ara Egipti yio ṣe sọ wipe, Nitori ibi li o ṣe mú wọn jade, lati pa wọn lori oke, ati lati run wọn kuro lori ilẹ? Yipada kuro ninu ibinu rẹ ti o muna, ki o si yi ọkàn pada niti ibi yi si awọn enia rẹ.

13 Ranti Abrahamu, Isaaki, ati Israeli awọn iranṣẹ rẹ, ẹniti iwọ fi ara rẹ bura fun, ti iwọ si wi fun wọn pe, Emi o mu irú-ọmọ nyin bisi i bi irawọ ọrun, ati gbogbo ilẹ na ti mo ti sọ nì, irú-ọmọ nyin li emi o fi fun, nwọn o si jogún rẹ̀ lailai.

14 OLUWA si yi ọkàn pada niti ibi na ti o ti sọ pe on o ṣe si awọn enia rẹ̀.

15 Mose si yipada, o si sọkalẹ lati ori òke na wá, walã ẹri meji nì si wà li ọwọ́ rẹ̀; walã ti a kọwe si ni ìha mejeji; lara ekini ati ekeji li a kọwe si.

16 Iṣẹ Ọlọrun si ni walã wọnni, ikọwe na ni ikọwe Ọlọrun, a fin i sara walã na.

17 Nigbati Joṣua si gbọ́ ariwo awọn enia na, bi nwọn ti nhó, o wi fun Mose pe, Ariwo ogun mbẹ ni ibudó.

18 Mose si wi pe, Ki iṣe ohùn ariwo awọn ti nhó nitori iṣẹgun, bẽni ki iṣe ohùn ariwo awọn ti nkigbe pe a ṣẹgun wọn: ohùn awọn ti nkọrin ni mo gbọ́ yi.

19 O si ṣe, bi o ti sunmọ ibudó, o si ri ẹgbọrọmalu na, ati agbo ijó: ibinu Mose si ru gidigidi, o si sọ walã wọnni silẹ kuro li ọwọ́ rẹ̀, o si fọ́ wọn nisalẹ òke na.

20 O si mú ẹgbọrọ-malu na ti nwọn ṣe, o si sun u ni iná, o si lọ̀ ọ di ẹ̀tu, o si kù u soju omi, o si mu awọn ọmọ Israeli mu u.

21 Mose si wi fun Aaroni pe, Kili awọn enia wọnyi fi ṣe ọ, ti iwọ fi mú èṣẹ nla wá sori wọn?

22 Aaroni si wipe, Máṣe jẹ ki ibinu oluwa mi ki o gbona: iwọ mọ̀ awọn enia yi pe, nwọn buru.

23 Awọn li o sa wi fun mi pe, Ṣe oriṣa fun wa, ti yio ma ṣaju wa: bi o ṣe ti Mose yi ni, ọkọnrin nì ti o mú wa gòke lati ilẹ Egipti wá, awa kò mọ̀ ohun ti o ṣe e.

24 Emi si wi fun wọn pe, Ẹnikẹni ti o ba ní wurà, ki nwọn ki o kán a kuro; bẽni nwọn fi fun mi: nigbana li emi fi i sinu iná, ẹgbọrọmalu yi si ti jade wá.

25 Nigbati Mose ri i pe awọn enia na kò ṣe ikoso; nitoriti Aaroni sọ wọn di alailakoso lãrin awọn ti o dide si wọn.

26 Nigbana ni Mose duro li ẹnubode ibudó, o si wipe, Ẹnikẹni ti o wà ni ìha ti OLUWA, ki o tọ̀ mi wá. Gbogbo awọn ọmọ Lefi si kó ara wọn jọ sọdọ rẹ̀.

27 O si wi fun wọn pe, Bayi li OLUWA, Ọlọrun Israeli, wipe, Ki olukuluku ọkọnrin ki o kọ idà rẹ̀ si ẹgbẹ́ rẹ̀, ki ẹ si ma wọle, ki ẹ si ma jade lati ẹnubode dé ẹnubode já gbogbo ibudó, olukuluku ki o si pa arakọnrin rẹ̀, ati olukuluku ki o si pa ẹgbẹ rẹ̀, ati olukuluku ki o si pa aladugbo rẹ̀.

28 Awọn ọmọ Lefi si ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ Mose: awọn ti o ṣubu ninu awọn enia li ọjọ́ na to ìwọn ẹgbẹ̀dogun enia.

29 Mose sa ti wipe, Ẹ yà ara nyin simimọ́ li oni fun OLUWA, ani olukuluku ọkọnrin lara ọmọ rẹ̀, ati lara arakọnrin rẹ̀; ki o le fi ibukún si nyin lori li oni.

30 O si ṣe ni ijọ́ keji, ni Mose wi fun awọn enia pe, Ẹnyin dá ẹ̀ṣẹ nla: njẹ nisisiyi, emi o gòke tọ̀ OLUWA, bọya emi o ṣètutu fun ẹ̀ṣẹ nyin.

31 Mose si pada tọ̀ OLUWA lọ, o si wipe, Yẽ, awọn enia wọnyi ti dá ẹ̀ṣẹ nla, nwọn si dá oriṣa wurà fun ara wọn.

32 Nisisiyi, bi iwọ o ba dari ẹ̀ṣẹ wọn jì wọn—; bi bẽ si kọ, emi bẹ̀ ọ, pa mi rẹ́ kuro ninu iwé rẹ ti iwọ ti kọ.

33 OLUWA si wi fun Mose pe, Ẹnikẹni ti o ṣẹ̀ mi, on li emi o parẹ́ kuro ninu iwé mi.

34 Njẹ nisisiyi lọ, ma mú awọn enia na lọ si ibiti mo ti sọ fun ọ: kiyesi i, angeli mi yio ṣaju rẹ: ṣugbọn li ọjọ́ ti emi o ṣe ìbẹwo, emi o bẹ̀ ẹ̀ṣẹ wọn wò lara wọn.

35 OLUWA si yọ awọn enia na lẹnu, nitoriti nwọn ṣe ẹgbọrọ-malu, ti Aaroni ṣe.

## ORI 33.

OLUWA si wi fun Mose pe, Dide, gòke lati ihin lọ, iwọ ati awọn enia na ti iwọ mú gòke lati ilẹ Egipti wá, si ilẹ ti mo ti bura fun Abrahamu, fun Isaaki, ati fun Jakobu, wipe, Irú-ọmọ rẹ li emi o fi i fun:

2 Emi o si rán angeli kan si iwaju rẹ; emi o si lé awọn ara Kenaani, awọn ara Amori, ati awọn ara Hitti, ati awọn ara Perissi, ati awọn ara Hifi, ati awọn ara Jebusi jade:

3 Si ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin; emi ki yio sa gòke lọ lãrin rẹ; nitori ọlọrùn lile ni iwọ: ki emi ki o má ba run ọ li ọ̀na.

4 Nigbati awọn enia na si gbọ́ ihin buburu yi, nwọn kãnu: enia kan kò si wọ̀ ohun ọṣọ́ rẹ̀.

Digitized by Google

5 OLUWA si ti wi fun Mose pe, Wi fun awọn ọmọ Israeli pe, Ọlọrùn lile ni nyin: bi emi ba gòke wá sãrin rẹ ni iṣẹju kan, emi o si run ọ: njẹ nisisiyi bọ́ ohun ọṣọ́ rẹ kuro lara rẹ, ki emi ki o le mọ̀ ohun ti emi o fi ọ ṣe.

6 Awọn ọmọ Israeli si bọ́ ohun ọṣọ́ wọn kuro lara wọn leti oke Horebu.

7 Mose si mú agọ́ na, o si pa a lẹhin ibudó, li òkere réré si ibudó; o pè e ni Agọ́ ajọ. O si ṣe, olukuluku ẹniti mbère OLUWA o jade lọ si agọ́ ajọ, ti o wà lẹhin ibudó.

8 O si ṣe, nigbati Mose jade lọ si ibi agọ́ na, gbogbo awọn enia a si dide duro, olukuluku a si duro li ẹnu-ọ̀na agọ́ rẹ̀, a ma wò ẹhin Mose, titi yio fi dé ibi agọ́ na.

9 O si ṣe, bi Mose ti dé ibi agọ́ na, ọwọ̀n awọsanma sọkalẹ, o si duro li ẹnu-ọ̀na agọ́ na: OLUWA si bá Mose sọ̀rọ.

10 Gbogbo enia si ri ọwọ̀n awọsanma na o duro li ẹnu-ọ̀na agọ́ na: gbogbo enia si dide duro, nwọn si wolẹ sìn, olukuluku li ẹnu-ọ̀na agọ́ rẹ̀.

11 OLUWA si bá Mose sọ̀rọ li ojukoju, bi enia ti ibá ọ̀rẹ́ rẹ̀ sọ̀rọ. O si tun pada lọ si ibudó: ṣugbọn Joṣua iranṣẹ rẹ̀, ọmọ Nuni, ọdọmọkọnrin kan, kò lọ kuro ninu agọ́ na.

12 Mose si wi fun OLUWA pe, Wò o, iwọ wi fun mi pe, Mú awọn enia wọnyi gòke lọ: sibẹ̀ iwọ kò jẹ ki emi ki o mọ̀ ẹniti iwọ o rán pẹlu mi. Ṣugbọn iwọ wipe, Emi mọ̀ ọ li orukọ, iwọ si ri ore-ọfẹ li oju mi pẹlu.

13 Njẹ nisisiyi, emi bẹ̀ ọ, bi mo ba ri ore-ọfẹ li oju rẹ, fi ọ̀na rẹ hàn mi nisisiyi, ki emi ki o le mọ̀ ọ, ki emi ki o le ri ore-ọfẹ li oju rẹ: ki o si rò pe orilẹ-èdè yi enia rẹ ni.

14 On si wipe, Oju mi yio ma bá ọ lọ, emi o si fun ọ ni isimi.

15 On si wi fun u pe, Bi oju rẹ kò ba bá wa lọ, máṣe mú wa gòke lati ihin lọ.

16 Nipa ewo li a o fi mọ̀ nihinyi pe, emi ri ore-ọfẹ li oju rẹ, ani emi ati awọn enia rẹ? ki iha iṣe ni ti pe iwọ mbá wa lọ ni, bẽli a o si yà wa sọtọ̀, emi ati awọn enia rẹ, kuro lara gbogbo enia ti o wà lori ilẹ?

17 OLUWA si wi fun Mose pe, Emi o ṣe ohun yi ti iwọ sọ pẹlu: nitoriti iwọ ri ore-ọfẹ li oju mi, emi si mọ̀ ọ li orukọ.

18 O si wi fun u pe, Emi bẹ̀ ọ, fi ogo rẹ̀ hàn mi.

19 On si wi fun u pe, Emi o mu gbogbo ore mi kọja niwaju rẹ, emi o si pè orukọ OLUWA niwaju rẹ; emi o si ṣe ore-ọfẹ fun ẹniti emi nfẹ ṣe ore-ọfẹ fun, emi o si ṣe ãnu fun ẹniti emi o ṣe ãnu fun.

20 On si wipe, Iwọ kò le ri oju mi: nitoriti kò sí enia kan ti iri mi, ti si yè.

21 OLUWA si wipe, Wõ, ibi kan wà lẹba ọdọ mi, iwọ o si duro lori apata:

22 Yio si ṣe, nigbati ogo mi ba nrekọja, emi o fi ọ sinu pàlapala apata, emi o si fi ọwọ́ mi bò ọ titi emi o fi rekọja:

23 Nigbati emi o mú ọwọ́ mi kuro, iwọ o si ri akẹhinsi mi: ṣugbọn oju mi li a ki iri.

## ORI 34.

OLUWA si wi fun Mose pe, Iwọ gbẹ́ walã okuta meji bi ti iṣaju: emi o si kọ ọ̀rọ walã ti iṣaju, ti iwọ ti fọ́, sara walã wọnyi.

2 Si mura li owurọ̀, ki iwọ ki o si gùn òke Sinai wá li owurọ̀, ki o si wá duro niwaju mi nibẹ̀ lori òke na.

3 Ẹnikẹni ki yio si bá ọ gòke wá, ki a má si ṣe ri ẹnikẹni pẹlu li òke na gbogbo; bẹ̃ni ki a máṣe jẹ ki agbo-agutan tabi ọwọ́ẹran ki o jẹ niwaju òke na.

4 On si gbẹ́ walã okuta meji bi ti iṣaju; Mose si dide ni kutukutu owurọ̀, o si gùn òke Sinai, bi OLUWA ti paṣẹ fun u, o si mú walã okuta mejeji li ọwọ́ rẹ̀.

5 OLUWA si sọkalẹ ninu awọsanma, o si bá a duro nibẹ̀, o si pè orukọ OLUWA.

6 OLUWA si rekọja niwaju rẹ̀, o si nkepè, OLUWA, OLUWA, Ọlọrun alãnuati olore-ọfẹ, onipamọra, ati ẹniti o pọ̀ li ore ati otitọ;

7 Ẹniti o npa ãnu mọ́ fun ẹgbẹgbẹrun, ti o ndari aiṣedede, ati irekọja, ati ẹ̀ṣẹ jì, ati nitõtọ ti ki ijẹ ki ẹlẹbi lọ laijiyà; a ma bẹ̀ ẹ̀ṣẹ awọn baba wò lara awọn ọmọ, ati lara awọn ọmọ ọmọ, lati irandiran ẹkẹta ati ẹkẹrin.

8 Mose si yará, o si foribalẹ, o si sìn.

9 On si wipe, Njẹ bi mo ba ri ore-ọfẹ li oju rẹ nisisiyi Oluwa, emi bẹ̀ ọ, jẹ ki Oluwa ki o ma bá wa lọ; nitori enia ọlọrùn lile ni; ki o si dari aiṣedede wa ati ẹ̀ṣẹ wa jì, ki o si fi wa ṣe iní rẹ.

10 On si wipe, Kiyesi i, emi dá majẹmu kan: emi o ṣe ohun iyanu, niwaju gbogbo awọn enia rẹ, irú eyiti a kò ti iṣe lori ilẹ gbogbo rí, ati ninu gbogbo orilẹ-èdè: ati gbogbo enia ninu awọn ti iwọ wà, nwọn o ri iṣẹ OLUWA, nitori ohun ẹ̀ru li emi o fi ọ ṣe.

11 Iwọ kiyesi eyiti emi palaṣẹ fun ọ li oni yi: kiyesi i, emi lé awọn Amori jade niwaju rẹ, ati awọn ara Kenaani, ati awọn

Digitized by Google

ara Hitti, ati awọn ara Perissi, ati awọn ara Hifi, ati awọn ara Jebusi.

12 Ma ṣọ́ ara rẹ ki iwọ ki o má ba bá awọn ara ilẹ na dá majẹmu, nibikibi ti iwọ nlọ, ki o má ba di idẹwò fun ọ lãrin rẹ:

13 Bikoṣepe ki ẹnyin ki o wó pẹpẹ wọn, ki ẹnyin ki o fọ́ ọwọ̀n wọn, ki ẹnyin si wó ere-oriṣa wọn lulẹ.

14 Nitoriti ẹnyin kò gbọdọ bọ oriṣa: nitori OLUWA, orukọ ẹniti ijẹ Ojowu, Ọlọrun ojowú li on:

15 Ki iwọ ki o má ba bá awọn ara ilẹ na dá majẹmu, nigbati nwọn ba nṣe àgbere tọ̀ oriṣa wọn, ti nwọn si nrubọ si oriṣa wọn, ti nwọn si pè ọ, ti iwọ si lọ jẹ ninu ẹbọ wọn;

16 Ki iwọ ki o má si ṣe fẹ́ ninu awọn ọmọbirin wọn fun awọn ọmọkọnrin rẹ, ki awọn ọmọbirin wọn ki o má ba ṣe àgbere tọ̀ oriṣa wọn, ki nwọn ki o má ba mu ki awọn ọmọkọnrin rẹ ki o ṣe àgbere tọ̀ oriṣa wọn.

17 Iwọ kò gbọdọ yá ere oriṣakoriṣa kan fun ara rẹ.

18 Ajọ aiwukàra ni ki iwọ ki o ma pamọ́. Ijọ́ meje ni iwọ o jẹ àkara alaiwu, bi mo ti paṣẹ fun ọ, ni ìgba oṣù Abibu: nitoripe li oṣù Abibu ni iwọ jade kuro ni Egipti.

19 Gbogbo akọ́bi ni ti emi; ati akọ ninu gbogbo ohunọ̀sin rẹ; akọ́bi ti malu, ati ti agutan.

20 Ṣugbọn akọ́bi kẹtẹkẹtẹ ni ki iwọ ki o fi ọdọ-agutan rapada: bi iwọ kò ba si rà a pada, njẹ ki iwọ ki o ṣẹ́ ẹ li ọrùn. Gbogbo akọ́bi ninu awọn ọmọkọnrin rẹ ni ki iwọ ki o rapada. Kò si sí ẹnikan ti yio farahàn niwaju mi lọwọ ofo.

21 Ijọ́ mẹfa ni ki iwọ ki o ṣe iṣẹ, ṣugbọn ni ijọ́ keje ni ki iwọ ki o simi: ni ìgba ifunrugbìn, ati ni ìgba ikore ni ki iwọ ki o simi.

22 Iwọ o si ma kiyesi ajọ ọ̀sẹ, akọ́so eso alikama, ati ajọ ikore li opin ọdún.

23 Li ẹrinmẹta li ọdún kan ni gbogbo awọn ọmọkọnrin rẹ yio farahàn niwaju Oluwa ỌLỌRUN, Ọlọrun Israeli.

24 Nitoriti emi o lé awọn orilẹ-ède nì jade niwaju rẹ, emi o si fẹ̀ ipinlẹ rẹ: bẽli ẹnikẹni ki yio fẹ́ ilẹ-iní rẹ, nigbati iwọ o gòke lọ lati pejọ niwaju OLUWA Ọlọrun rẹ li ẹrinmẹta li ọdún kan.

25 Iwọ kò gbọdọ ta ẹ̀jẹ ẹbọ mi silẹ nibiti iwukàra wà, bẽli ẹbọ ajọ irekọja kò gbọdọ kù titi di owurọ̀.

26 Akọ́so eso ilẹ rẹ ni ki iwọ ki o mú wa si ile OLUWA Ọlọrun rẹ. Iwọ kò gbọdọ bọ̀ ọmọ ewurẹ ninu warà iya rẹ̀.

27 OLUWA si wi fun Mose pe, Iwọ kọwe ọ̀rọ wọnyi: nitori nipa ìmọ ọ̀rọ wọnyi li emi bá iwọ ati Israeli dá majẹmu.

28 On si wà nibẹ̀ lọdọ OLUWA li ogoji ọsán ati ogoji oru: on kò jẹ onjẹ, bẽni kò mu omi. On si kọwe ọ̀rọ majẹmu na, ofin mẹwa nì, sara walã wọnni.

29 O si ṣe, nigbati Mose sọkalẹ lati ori òke Sinai wá ti on ti walã ẹrí mejeji nì li ọwọ́ Mose, nigbati o sọkalẹ ti ori òke na wá, ti Mose kò mọ̀ pe awọ oju on ndán nitoriti O bá a sọ̀rọ.

30 Nigbati Aaroni ati gbogbo awọn ọmọ Israeli ri Mose, kiyesi i, awọ oju rẹ̀ ndán; nwọn si bẹ̀ru lati sunmọ ọdọ rẹ̀.

31 Mose si kọ si wọn; ati Aaroni ati gbogbo awọn ijoye inu ajọ si pada tọ̀ ọ wá: Mose si bá wọn sọ̀rọ.

32 Lẹhin eyinì ni gbogbo awọn ọmọ Israeli si sunmọ ọ: o si paṣẹ gbogbo ohun ti OLUWA bá a sọ lori òke Sinai fun wọn.

33 Nigbati Mose si bá wọn sọ̀rọ tán, o fi iboju bò oju rẹ̀.

34 Ṣugbọn nigbati Mose ba lọ si iwaju OLUWA lati bá a sọ̀rọ, a mú iboju na kuro titi o fi jade: a si jade, a si bá awọn ọmọ Israeli sọ̀rọ aṣẹ ti a pa fun u.

35 Awọn ọmọ Israeli si ri oju Mose pe, àwọ oju rẹ̀ ndán: Mose si tun fi iboju bò oju rẹ̀, titi o fi wọle lọ bá a sọ̀rọ.

## ORI 35.

MOSE si pè apejọ gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli, o si wi fun wọn pe, Wọnyi li ọ̀rọ ti OLUWA palaṣẹ pe, ki ẹnyin ki o ṣe wọn.

2 Ijọ́ mẹfa ni ki a fi ṣe iṣẹ, ṣugbọn ijọ́ keje ni yio ṣe ọjọ́ mimọ́ fun nyin, ọjọ́ isimi ọ̀wọ si OLUWA: ẹnikẹni ti o ba ṣe iṣẹ ninu rẹ̀ li a o lupa nitõtọ.

3 Ẹnyin kò gbọdọ da iná ni ile nyin gbogbo li ọjọ́ isimi.

4 Mose si sọ fun gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli pe, Eyi li ohun ti OLUWA palaṣẹ, wipe,

5 Ẹnyin mú ọrẹ wá lati inu ara nyin fun OLUWA: ẹnikẹni ti ọkàn rẹ̀ fẹ́, ki o mú u wá, li ọrẹ fun OLUWA; wurà, ati fadakà, ati idẹ;

6 Ati aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ didara, ati irun ewurẹ;

7 Ati awọ àgbo ti a sè ni pupa, ati awọ seali, ati igi ṣittimu;

8 Ati oróro fun fitila, ati olõrùn fun oróro itasori, ati fun turari didùn;

9 Ati okuta oniki, ati okuta ti a o tò si ẹ̀wu-efodi, ati si igbàiya.

Digitized by Google

10 Gbogbo ọlọgbọ́n inu ninu nyin yio si wá, yio si wá ṣiṣẹ gbogbo ohun ti OLUWA palaṣẹ;

11 Ibugbé na, ti on ti agọ́ rẹ̀, ati ibori rẹ̀, kọkọrọ rẹ̀, ati apáko rẹ̀, ọpá rẹ̀, ọwọ̀n rẹ̀, ati ihò-ìtẹbọ rẹ̀;

12 Apoti nì, ati ọpá rẹ̀, itẹ́-ãnu nì, ati aṣọ-ikele na;

13 Tabili na, ati ọpá rẹ̀, ati ohun-èlo rẹ̀ gbogbo, ati àkara ifihàn nì;

14 Ati ọpà-fitila na fun titanna, ati ohun-èlo rẹ̀, ati fitila rẹ̀, pẹlu oróro fun titanna.

15 Ati pẹpẹ turari, ati ọpá rẹ̀, ati oróro itasori, ati turari didùn, ati aṣọ-sisorọ̀ fun ẹnu-ọ̀na, ani atiwọle ẹnu agọ́ na;

16 Ati pẹpẹ ẹbọsisun, ti on ti àwọn oju-àro idẹ rẹ̀, ati ọpá rẹ̀, ati gbogbo ohun-èlo rẹ̀, agbada na ti on ti ẹsẹ rẹ̀;

17 Aṣọ-isorọ̀ ti agbalá, ọwọ̀n rẹ̀, ati ihò-ìtẹbọ rẹ̀, ati aṣọ-isorọ̀ fun ẹnu-ọ̀na agbalá na;

18 Ekàn agọ́ na, ati ekàn agbalá na, ati okùn wọn;

19 Aṣọ ìsin wọnni, lati sìn ni ibi mimọ́, aṣọ mimọ́ wọnni fun Aaroni alufa, ati aṣọ awọn ọmọ rẹ̀, lati ma fi ṣe iṣẹ alufa.

20 Gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli si lọ kuro ni iwaju Mose.

21 Nwọn si wá, olukuluku ẹniti ọkàn rẹ̀ ru ninu rẹ̀, ati olukuluku ẹniti ọkàn rẹ̀ mu u fẹ́, nwọn si mú ọrẹ OLUWA wá fun iṣẹ agọ́ ajọ na, ati fun ìsin rẹ̀ gbogbo, ati fun aṣọ mimọ́ wọnni.

22 Nwọn si wá, ati ọkọnrin ati obirin, iye awọn ti ọkàn wọn fẹ́, nwọn si mú jufù wá, ati oruka-eti, ati oruka-àmi, ati ilẹkẹ wurà, ati onirũru ohun wurà; ati olukuluku enia ti o nta ọrẹ, o ta ọrẹ wurà fun OLUWA.

23 Ati olukuluku enia lọdọ ẹniti a ri aṣọ-alaró, ati elesè àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ daradara, ati irun ewurẹ, ati awọ àgbo pupa, ati awọ seali, mú wọn wá.

24 Olukuluku ẹniti o ta ọrẹ fadakà ati idẹ, o mú ọrẹ OLUWA wá: ati olukuluku enia lati ọdọ ẹniti a ri igi ṣittimu fun iṣẹ-kiṣẹ ìsin na, mú u wá.

25 Ati gbogbo awọn obirin ti iṣe ọlọgbọ́n inu, nwọn fi ọwọ́ wọn ranwu, nwọn si mú eyiti nwọn ran wá, ti alaró, ati ti elesè-àluko, ati ti ododó, ati ti ọ̀gbọ daradara.

26 Ati gbogbo awọn obirin inu ẹniti o ru soke li ọgbọ́n nwọn ran irun ewurẹ.

27 Ati awọn ijoye mú okuta oniki wá, ati okuta ti a o tò, fun ẹ̀wu-efodi nì, ati fun igbàiya nì;

28 Ati olõrùn, ati oróro; fun fitila, ati fun oróro itasori, ati fun turari didùn.

29 Awọn ọmọ Israeli ta ọrẹ atinuwa fun OLUWA; olukuluku ọkọnrin ati obirin, ẹniti ọkàn wọn mu wọn fẹ́ lati mú u wá, fun onirũru iṣẹ, ti OLUWA palaṣẹ ni ṣiṣe lati ọwọ́ Mose wá,

30 Mose si wi fun awọn ọmọ Israeli pe, Wò o, OLUWA ti pè Besaleli ọmọ Uri, ọmọ Huri, ti ẹ̀ya Judah, li orukọ.

31 O si fi ẹmi Ọlọrun kún u li ọgbọ́n, li oyé, ni ìmọ, ati li onirũru iṣẹ-ọnà;

32 Ati lati humọ̀ alarabara iṣẹ, lati ṣiṣẹ ni wurà, ati ni fadakà, ati ni idẹ,

33 Ati li okuta gbigbẹ́ lati tò wọn, ati ni igi fifin, lati ṣiṣẹ li onirũru iṣẹ-ọnà.

34 O si fi sinu ọkàn rẹ̀ lati ma kọni, ati on, ati Oholiabu, ọmọ Ahisamaki, ti ẹ̀ya Dani.

35 O si fi ọgbọ́n inu kún wọn, lati ṣe onirũru iṣẹ, ti alagbẹdẹ, ati ti ọnà, ati ti agunnà, li aṣọ-alaró, ati li elesè-àluko, li ododó, ati li ọ̀gbọ daradara, ati ti awunṣọ, ati ti awọn ẹniti nṣe iṣẹkiṣẹ, ati ti awọn ẹniti nhumọ̀ iṣẹ-ọnà.

## ORI 36.

BESALELI ati Oholiabu yio si ṣiṣẹ, ati olukuluku ọlọgbọ́n inu, ninu ẹniti OLUWA fi ọgbọ́n ati oyé si, lati mọ̀ bi ati ṣiṣẹ onirũru iṣẹ ìsin ibi mimọ́ na, gẹgẹ bi gbogbo ohun ti OLUWA ti palaṣẹ.

2 Mose si pè Besaleli ati Oholiabu, ati gbogbo ọkọnrin ọlọgbọ́n inu, ninu ọkàn ẹniti OLUWA fi ọgbọ́n si, ani gbogbo ẹniti inu wọn ru soke lati wá si ibi iṣẹ na lati ṣe e:

3 Nwọn si gbà gbogbo ọrẹ na lọwọ Mose, ti awọn ọmọ Israeli múwa fun iṣẹ ìsin ibi mimọ́ na, lati fi ṣe e. Sibẹ̀ nwọn si nmú ọrẹ ọfẹ fun u wá li orowurọ̀.

4 Ati gbogbo awọn ọkọnrin ọlọgbọ́n, ti o ṣe gbogbo iṣẹ ibi mimọ́ na, lọ olukuluku kuro ni ibi iṣẹ rẹ̀ ti nwọn ṣe;

5 Nwọn si sọ fun Mose pe, Awọn enia múwa pupọ̀ju fun iṣẹ ìsin na, ti OLUWA palaṣẹ ni ṣiṣe.

6 Mose si paṣẹ, nwọn si ṣe ki nwọn ki o kede yi gbogbo ibudó na ká, wipe, Máṣe jẹ ki ọkọnrin tabi obirin ki o tun ṣe iṣẹkiṣẹ fun ọrẹ ibi mimọ́ na mọ́. Bẹ̃li a da awọn enia lẹkun ati ma múwa.

7 Nitoriti ohun-èlo ti nwọn ní o to fun gbogbo iṣẹ na, lati fi ṣe e, o si pọ̀ju.

8 Ati olukuluku ọkọnrin ọlọgbọ́n ninu awọn ti o ṣe iṣẹ agọ́ na, nwọn ṣiṣẹ aṣọ-tita

Digitized by Google

mẹwa; ti ògbọ olokùn wiwẹ, ati ti aṣọ-alaró, ati ti elesè-àluko, ati ti ododó, pẹlu awọn kerubu, iṣẹ-ọnà li on fi ṣe wọn.

9 Ìna aṣọ-tita kan jẹ igbọnwọ mejidilọgbọn, ati ibò aṣọ-tita kan jẹ́ igbọnwọ mẹrin: gbogbo aṣọ-tita na jẹ́ ìwọn kanna.

10 O si so aṣọ-tita marun lù mọ́ ara wọn: ati aṣọ-tita marun keji li o si solù mọ́ ara wọn.

11 O si pa ojóbo aṣọ-alaró li eti aṣọ-tita kan lati iṣẹti rẹ̀ wá ni ibi isolù; bẽ gẹgẹ li o ṣe si ìha eti ikangun aṣọ-tita keji nibi isolù keji.

12 Ãdọta ojóbo li o pa lara aṣọ-tita kan, ati ãdọta ojóbo li o si pa li eti aṣọ-tita ti o wà ni isolù keji: ojóbo na so aṣọ-tita kini mọ́ keji.

13 O si ṣe ãdọta ikọ́ wurà o si fi ikọ́ wọnni fi aṣọ-tita kan kọ́ ekeji: bẽli o si di odidi agọ́.

14 O si ṣe aṣọ-tita irun ewurẹ fun agọ́ na lori ibugbé na: aṣọ-tita mọkanla li o ṣe wọn.

15 Ìna aṣọ-tita kan jẹ́ ọgbọ̀n igbọnwọ, ibò aṣọ-tita kan si jẹ́ igbọnwọ mẹrin: aṣọ-tita mọkọkanla jẹ́ ìwọn kanna.

16 O si so aṣọ-tita marun lù mọ́ ara wọn, ati aṣọ-tita mẹfa lù mọ́ ara wọn.

17 O si pa ãdọta ojóbo si ìha eti ikangun aṣọ-tita na ni ibi isolù, ati ãdọta ojóbo li o si pa si eti aṣọ-tita ti o so ekeji lù.

18 O si ṣe ãdọta ikọ́ idẹ lati so agọ́ na lù pọ̀, ki o le ṣe ọkan.

19 O si ṣe ibori awọ àgbo ti a sè ni pupa fun agọ́ na, ati ibori awọ seali lori eyi.

20 O si ṣe apáko igi ṣittimu fun agọ́ na li ogurodo.

21 Gigùn apáko kan jẹ́ igbọnwọ mẹwa, ati ibú apáko kan jẹ́ igbọnwọ kan on àbọ.

22 Apáko kan ní ìtẹbọ meji, nwọn jìna si ara wọn li ọgbọgba; bẽli o ṣe sara gbogbo apáko agọ́ na.

23 O si fi apáko ṣe agọ́ na; ogún apáko ni fun ìha ọtún, si ìha gusù:

24 Ati ogoji ihò-ìtẹbọ fadakà li o ṣe nisalẹ ogún apáko wọnni; ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko kan fun ìtẹbọ rẹ̀ meji, ati ihò-ìtẹbọ rẹ̀ meji nisalẹ apáko keji fun ìtẹbọ rẹ̀ meji.

25 Ati fun ìha keji agọ́ na, ti o wà ni ìha ariwa, o ṣe ogún apáko,

26 Ati ogoji ihò-ìtẹbọ wọn ti fadakà; ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko kan, ati ihò-ìtẹbọ meji nisalẹ apáko keji.

27 Ati fun ìha agọ́ na ni ìha ìwọ-õrùn o ṣe apáko mẹfa.

28 Apáko meji li o ṣe fun igun agọ́ na ni ìha mejeji.

29 A si so wọn lù nisalẹ, a si so wọn lù pọ̀ li ori rẹ̀, si oruka kan: bẽli o ṣe si awọn meji ni igun mejeji.

30 Apáko mẹjọ li o wà, ihò-ìtẹbọ wọn si jẹ́ ihò-ìtẹbọ mẹrindilogun ti fadakà; ìtẹbọ mejimeji li o wà nisalẹ apáko kọkan.

31 O si ṣe ọpá igi ṣittimu; marun fun apáko ìha kan agọ́ na,

32 Ati ọpá marun fun apáko ìha keji agọ́ na, ati ọpá marun fun apáko agọ́ na fun ìha ìwọ-õrùn.

33 O si ṣe ọpá ãrin o yọ jade lara apáko wọnni, lati opin ekini dé ekeji.

34 O si fi wurà bò apáko wọnni, o si fi wurà ṣe oruka wọn, lati ṣe ipò fun ọpá wọnni, o si fi wurà bò ọpá wọnni.

35 O si fi aṣọ-alaró, ati ti elesè-àluko, ati ti ododó, ati ti ògbọ olokùn wiwẹ ṣe aṣọ-ikele: iṣẹ ọlọnà li o fi ṣe e ti on ti awọn kerubu.

36 O si ṣe opó igi ṣittimu mẹrin si i, o si fi wurà bọ wọn: kọkọrọ wọn ti wurà ni, o si dà ihò-ìtẹbọ fadakà mẹrin fun wọn.

37 O si ṣe aṣọ-isorọ̀ kan fun ẹnu-ọ̀na Agọ́ na, aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ògbọ olokùn wiwẹ, ti iṣẹ abẹ́rẹ;

38 Ati opó rẹ̀ mararun ti on ti kọkọrọ wọn: o si fi wurà bò ọnà ori wọn, ati ọjá wọn: ṣugbọn idẹ ni ihò-ìtẹbọ wọn mararun.

## ORI 37.

BESALELI si fi igi ṣittimu ṣe apoti na: igbọnwọ meji on àbọ ni gigùn rẹ̀, ati igbọnwọ kan on àbọ ni ibú rẹ̀, igbọnwọ kan on àbọ si ni giga rẹ̀:

2 O si fi kìki wurà bò o ninu ati lode, o si ṣe igbáti wurà si i yiká.

3 O si dà oruka wurà mẹrin fun u, lati fi si igun mẹrẹrin rẹ̀; oruka meji si ìha kini rẹ̀, ati meji si ìha keji rẹ̀.

4 O si fi igi ṣittimu ṣe ọpá, o si fi wurà bò wọn.

5 O si fi ọpá wọnni bọ̀ inu oruka wọnni ni ìha apoti na, lati ma rù apoti na.

6 O si fi kìki wurà ṣe itẹ́-ãnu na: igbọnwọ meji on àbọ ni gigùn rẹ̀, ati igbọnwọ kan on àbọ ni ibú rẹ̀.

7 O si ṣe kerubu wurà meji; iṣẹ lilù li o ṣe wọn, ni ìku mejeji itẹ́-ãnu na;

8 Kerubu kan ni ìku kini, ati kerubu keji ni ìku keji: lati ara itẹ́-ãnu li o ti ṣe awọn kerubu na ni ìku mejeji rẹ̀.

9 Awọn kerubu na si nà iyẹ́-apa wọn

Digitized by Google

soke, nwọn si fi iyẹ́-apa wọn bò itẹ́-ãnu na, nwọn si dojukọ ara wọn; itẹ́-ãnu na ni awọn kerubu kọjusi.

10 O si fi igi ṣittimu ṣe tabili kan: igbọnwọ meji ni gigùn rẹ̀, ati igbọnwọ kan ni ibú rẹ̀, igbọnwọ kan on àbọ si ni giga rẹ̀:

11 O si fi kìki wurà bò o, o si ṣe igbáti wurà si i yiká.

12 O si ṣe eti kan bi ibú-atẹlẹwọ si i yiká, o si ṣe igbáti wurà kan fun eti rẹ̀ yiká.

13 O si dà oruka wurà mẹrin fun u, o si fi oruka wọnni si igun mẹrẹrin, ti o wà ni ibi ẹsẹ̀ mẹrẹrin rẹ̀.

14 Labẹ igbáti na ni oruka wọnni wà, àye fun ọpá lati fi rù tabili na.

15 O si fi igi ṣittimu ṣe ọpá wọnni, o si fi wurà bò wọn, lati ma rù tabili na.

16 O si ṣe ohunèlo wọnni ti o wà lori tabili na, awopọkọ rẹ̀, ati ṣibi rẹ̀, ati awokòto rẹ̀, ati igo rẹ̀, lati ma fi dà ohun mimu, kìki wurà ni.

17 O si fi kìki wurà ṣe ọpá fitila: iṣẹ lilù li o ṣe ọpà-fitila na; ọpá rẹ̀, ati ẹka rẹ̀, ago rẹ̀, irudi rẹ̀, ati itanna rẹ̀, okanna ni nwọn:

18 Ẹka mẹfa li o jade ni ìha rẹ̀; ẹka mẹta ọpá-fitila na ni ìha kan rẹ̀, ati ẹka mẹta ọpá-fitila na, ni ìha keji rẹ̀.

19 Ago mẹta ti a ṣe bi itanna almondi li ẹka kan, irudi kan ati itanna; ati ago mẹta ti a ṣe bi itanna almondi li ẹka keji, irudi kan ati itanna: bẹ̃ni li ẹka mẹfẹfa ti o jade lara ọpá-fitila na.

20 Ati ninu ọpá-fitila na li a ṣe ago mẹrin bi itanna almondi, irudi rẹ̀, ati itanna rẹ̀:

21 Ati irudi kan nisalẹ ẹka meji lara rẹ̀, ati irudi kan nisalẹ ẹka meji lara rẹ̀, ati irudi kan nisalẹ ẹka meji lara rẹ̀, gẹgẹ bi ẹka mẹfẹfa ti o jade lara rẹ̀.

22 Irudi wọn ati ẹka wọn jẹ́ bakanna: gbogbo rẹ̀ jẹ́ iṣẹ lilù kìki wurà kan.

23 O si ṣe fitila rẹ̀, meje, ati alumagaji rẹ̀, ati awo rẹ̀, kìki wurà ni.

24 Talenti kan kìki wurà li o fi ṣe e, ati gbogbo ohunèlo rẹ̀.

25 O si fi igi ṣittimu ṣe pẹpẹ turari: gigùn rẹ̀ jẹ́ igbọnwọ kan, ibú rẹ̀ si jẹ́ igbọnwọ kan, ìha mẹrin ọgbọgba; giga rẹ̀ si jẹ́ igbọnwọ meji; iwo rẹ̀ wà lara rẹ̀.

26 O si fi kìki wurà bò o, ati òke rẹ̀, ati ìha rẹ̀ yiká, ati iwo rẹ̀: o si ṣe igbáti wurà si i yiká.

27 O si ṣe oruka wurà meji si i nisalẹ̀ igbáti rẹ̀ na, ni ìha igun rẹ̀ meji, ìha mejeji rẹ̀, lati ṣe àye fun ọpá wọnni lati ma fi rù u.

28 O si fi igi ṣittimu ṣe ọpá wọnni, o si fi wurà bò wọn.

29 O si ṣe oróro mimọ́ itasori nì, ati õrùn didùn kìki turari, gẹgẹ bi iṣẹ alapòlu.

## ORI 38.

O SI fi igi ṣittimu ṣe pẹpẹ ẹbọsisun: igbọnwọ marun ni gigùn rẹ̀, ati igbọnwọ marun ni ibú rẹ̀; onìha mẹrin ọgbọgba ni; igbọnwọ mẹta si ni giga rẹ̀.

2 O si ṣe iwo rẹ̀ si i ni igun rẹ̀ mẹrẹrin; iwo rẹ̀ wà lara rẹ̀: o si fi idẹ bò o.

3 O si ṣe gbogbo ohunèlo pẹpẹ na; ìkoko rẹ̀, ọkọ́ rẹ̀, ati awokòto rẹ̀, ati kọkọrọ ẹran rẹ̀, ati awo iná wọnni: gbogbo ohunèlo rẹ̀ li o fi idẹ ṣe.

4 O si ṣe àro idẹ fun pẹpẹ na ni iṣẹ àwọn nisalẹ ayiká rẹ̀, dé agbedemeji rẹ̀.

5 O si dà oruka mẹrin fun ìku mẹrẹrin àro idẹ na, li àye fun ọpá wọnni.

6 O si fi igi ṣittimu ṣe ọpá wọnni, o si fi idẹ bò wọn.

7 O si fi ọpá wọnni sinu oruka ni ìha pẹpẹ na, lati ma fi rù u; o fi apáko ṣe pẹpẹ na li onihò ninu.

8 O si fi idẹ ṣe agbada na, o si fi idẹ ṣe ẹsẹ̀ rẹ̀, ti awojiji ẹgbẹ awọn obirin ti npejọ lati sin li ẹnu-ọna agọ́ ajọ.

9 O si ṣe agbalá na: ni ìha gusù li ọwọ́ ọtún aṣọ-tita agbalá na jẹ́ ọ̀gbọ olokùn wiwẹ, ọgọrun igbọnwọ:

10 Opó wọn jẹ́ ogún, ihò-ìtẹbọ idẹ wọn jẹ́ ogún; kọkọrọ opó wọnni ati ọjá wọn jẹ́ fadakà.

11 Ati fun ìha ariwa ọgọrun igbọnwọ, opó wọn jẹ́ ogún, ati ihò-ìtẹbọ idẹ wọn jẹ́ ogún; kọkọrọ opó wọnni ati ọjá wọn jẹ́ fadakà.

12 Ati fun ìha ìwọ-õrùn li aṣọ-tita ãdọta igbọnwọ, opó wọn mẹwa, ati ihò-ìtẹbọ wọn mẹwa; kọkọrọ opó wọnni ati ọjá wọn jẹ́ fadakà.

13 Ati fun ìha ìla-õrùn, si ìha ìla-õrùn ãdọta igbọnwọ.

14 Aṣọ-tita apakan jẹ́ igbọnwọ mẹdogun; opó wọn jẹ́ mẹta, ati ihò-ìtẹbọ wọn jẹ́ mẹta.

15 Ati fun apa keji: li apa ìhin ati li apa ọ̀hún ẹnu-ọna agbalá na, li aṣọ-tita onigbọnwọ mẹdogun wà; opó wọn jẹ́ mẹta, ati ihò-ìtẹbọ̀ wọn jẹ́ mẹta.

16 Gbogbo aṣọ-tita agbalá na yiká jẹ́ ọ̀gbọ olokùn wiwẹ.

17 Ati ihò-ìtẹbọ fun opó wọnni jẹ́ idẹ; kọkọrọ opó wọnni ati ọjá wọn jẹ́ fadakà; ati ibori ori wọn jẹ́ fadakà; ati gbogbo opó agbalá na li a fi fadakà gbà li ọjá.

Digitized by Google

18 Ati aṣọ-isorọ̀ ẹnu-ọ̀na agbalá na jẹ́ iṣẹ abẹ́rẹ, aṣọ-alaró, ati elesè-aluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ olokùn wiwẹ: ogún igbọnwọ si ni gigùn rẹ̀, ati giga ni ibò rẹ̀ jẹ́ igbọnwọ marun, o bá aṣọ-tita agbalá wọnni ṣedede.

19 Opó wọn si jẹ́ mẹrin, ati ihò-ìtẹbọ wọn ti idẹ, mẹrin; kọkọrọ wọn jẹ́ fadakà, ati ibori ori wọn ati ọjá wọn jẹ́ fadakà.

20 Ati gbogbo ekàn agọ́ na, ati ti agbalá rẹ̀ yiká jẹ́ idẹ.

21 Eyi ni iye agọ́ na, agọ́ ẹrí nì, bi a ti kà wọn, gẹgẹ bi ofin Mose, fun ìsin awọn ọmọ Lefi, lati ọwọ́ Itamari wá, ọmọ Aaroni alufa.

22 Besaleli ọmọ Uri, ọmọ Huri, ti ẹ̀ya Judah, si ṣe ohun gbogbo ti OLUWA paṣẹ fun Mose.

23 Ati Oholiabu pẹlu rẹ̀, ọmọ Ahisamaki, ti ẹ̀ya Dani, alagbẹdẹ, ati ọlọgbọ́n ọlọnà, ati agunna li aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ didara.

24 Gbogbo wurà ti a lò si iṣẹ na, ni onirũru iṣẹ ibi mimọ́ nì, ani wurà ọrẹ nì, o jẹ́ talenti mọkandilọgbọ̀n, ati ẹgbẹrin ṣekeli o din ãdọrin, ni ìwọn ṣekeli ibi mimọ́.

25 Ati fadakà awọn ẹniti a kà ninu ijọenia jẹ́ ọgọrun talenti, ati ṣekeli ojidilẹgbẹsan o le mẹdogun, ni ìwọn ṣekeli ibi mimọ́:

26 Abọ ṣekeli kan li ori ọkọnrin kọkan, ni ìwọn ṣekeli ibi mimọ́, lori ori olukuluku ti o kọja sinu awọn ti a kà, lati ẹni ogún ọdún ati jù bẹ̃ lọ, jẹ́ ọgbọ̀n ọkẹ le egbẹtadilogun o le ãdọjọ enia.

27 Ati ninu ọgọrun talenti fadakà na li a ti dà ihò-ìtẹbọ wọnni ti ibi mimọ́, ati iho-ìtẹbọ ti aṣọ-ikele na, ọgọrun ihò-ìtẹbọ ninu ọgọrun talenti na, talenti kan fun ihò-ìtẹbọ kan.

28 Ati ninu ojidilẹgbẹsan ṣekeli o le mẹdogun, o mú ṣe kọkọrọ fun ọwọ̀n wọnni, o si fi i bò ori wọn, o si fi i ṣe ọjá wọn.

29 Ati idẹ ọrẹ na jẹ́ ãdọrin talenti, ati egbejila ṣekeli.

30 On li o si fi ṣe ihò-ìtẹbọ ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ ati pẹpẹ idẹ na, ati àro idẹ sara rẹ̀, ati gbogbo ohun-èlo pẹpẹ na,

31 Ati ihò-itẹbọ agbalá na yikà, ati ìho-ìtẹbọ ẹnu-ọna agbalá, ati gbogbo ekàn agọ́ na, ati gbogbo ekàn agbalá na yikà.

## ORI 39.

NWỌN si fi ninu aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, dá aṣọ ìsin, lati ma fi sin ni ibi mimọ́, nwọn si dá aṣọ mimọ́ ti iṣe fun Aaroni; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

2 O si ṣe ẹ̀wu-efodi na ti wurà, ati aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ olokùn wiwẹ.

3 Nwọn si lù wurà nì di ewé fẹlẹfẹlẹ, nwọn si là a li okùn wẹ́wẹ, ati lati fi ṣe iṣẹ ọlọnà sinu aṣọ-alarò, ati sinu elesè-àluko, ati sinu ododó, ati sinu ọ̀gbọ didara nì.

4 Nwọn ṣe aṣọ ejika si i, lati so o lù: li eti mejeji li a so o lù.

5 Ati onirũru-ọnà ọjá ti o wà lara rẹ̀, lati fi dì i, o jẹ́ ọkanna, gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀; ti wurà, aṣọ-alaró, elesè-àluko, ti ododó, ati ti ọ̀gbọ̀ olokùn wiwẹ; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

6 Nwọn si ṣiṣẹ okuta oniki ti a tò sinu oju-ìde wurà, ti a fin bi ifin èdidi-àmi ti a fin orukọ awọn ọmọ Israeli si.

7 O si fi wọn si ejika ẹ̀wu-efodi na, li okuta, iranti fun awọn ọmọ Israeli: bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

8 O si fi iṣẹ ọlọnà ṣiṣẹ igbàiya na, bi iṣẹ ẹ̀wu-efodi nì; ti wurà, ati aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ olokùn wiwẹ.

9 Oniha mẹrin ọgbọgba ni; nwọn ṣe igbàiya na ni iṣẹpo meji: ika kan ni gigùn rẹ̀, ika kan si ni ibú rẹ̀, o jẹ́ iṣẹpo meji.

10 Nwọn si tò ẹsẹ̀ okuta mẹrin si i: ẹsẹ̀ ekini ni sardiu, ati topasi, ati smaragdu; eyi li ẹsẹ̀ kini.

11 Ati ẹsẹ̀ keji, emeraldi, safiru, ati diamondi.

12 Ati ẹsẹ̀ kẹta, ligure, agate, ati ametistu.

13 Ati ẹsẹ̀ kẹrin, berilu, oniki, ati jasperi: a si tò wọn si oju-ìde wurà ni titò wọn.

14 Okuta wọnni si jasi gẹgẹ bi orukọ awọn ọmọ Israeli mejila, gẹgẹ bi orukọ wọn, bi ifin èdidi àmi, olukuluku ti on ti orukọ rẹ̀, gẹge bi ẹ̀ya mejejila.

15 Nwọn si ṣe ẹ̀wọn iṣẹ-ọnà-lilọ kìki wurà si igbàiya na.

16 Nwọn si ṣe oju-ìde wurà meji, ati oruka wurà meji; nwọn si fi oruka mejeji si eti igbàiya na mejeji.

17 Nwọn si fi ẹ̀wọn wurà iṣẹ-ọnà-lilọ mejeji bọ̀ inu oruka wọnni, ni eti igbàiya na.

18 Ati eti mejeji ti ẹ̀wọn iṣẹ-lilọ mejeji nì ni nwọn fi mọ́ inu oju-ìde mejeji, nwọn si fi wọn sara okùn ejika ẹ̀wu-efodi na niwaju rẹ̀.

19 Nwọn si ṣe oruka wurà meji, nwọn

Digitized by Google

si fi wọn si eti mejeji igbàiya na, si eti rẹ̀
ti o wà, ni ìha ẹ̀wu-efodi na ni ìha inu.
20 Nwọn si ṣe oruka wurà meji, nwọn si
fi wọn si ìha mejeji ẹ̀wu-efodi na nisalẹ, si
ìha iwaju rẹ̀, ki o kọjusi isolù rẹ̀, loke ọjá
ẹ̀wu-efodi na.
21 Nwọn si fi oruka rẹ̀ dè igbàiya na mọ́
oruka ẹ̀wu-efodi pẹlu ọjá-àwọn aṣọ-alaró, ki
o le ma wà lori onirũru-ọnà ọjá ẹ̀wu-efodi
na, ati ki igbàiya nì ki o máṣe tú kuro
lara ẹ̀wu-efodi na; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun
Mose.
22 O si ṣe aṣọ igunwa ẹ̀wu-efodi na ni
iṣẹ wiwun, gbogbo rẹ̀ jẹ́ aṣọ-alaro.
23 Oju-ọrùn si wà li agbedemeji aṣọ-
igunwa na, o dabi oju-ẹ̀wu ogun, pẹlu ọjá
yi oju na ká, ki o máṣe ya.
24 Nwọn si ṣe pomegranate aṣọ-alaró, ati
elesè-àluko, ati ododó, ati ọ̀gbọ olokùn
wiwẹ si iṣẹti aṣọ-igunwa na.
25 Nwọn si ṣe ṣaworo kìki wurà, nwọn
si fi ṣaworo na si alafo pomegranate wọnni
si eti iṣẹti aṣọ-igunwa na, yiká li alafo
pomegranate wọnni;
26 Ṣaworo kan ati pomegranate kan, ṣa-
woro kan ati pomegranate kan, yi iṣẹti aṣọ-
igunwa na ká lati ma fi ṣiṣẹ alufa; bi
OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.
27 Nwọn si ṣe ẹ̀wu ọ̀gbọ daradara ti iṣẹ
wiwun fun Aaroni, ati fun awọn ọmọ rẹ̀,
28 Ati fila ọṣọ́ ọ̀gbọ daradara, ati fila
ọ̀gbọ didara, ati ṣòkoto ọ̀gbọ olokun wiwẹ,
29 Ati ọjá ọ̀gbọ olokùn wiwẹ, ati ti aṣọ-
alaró, ti elesè-àluko, ati ti ododó, oniṣẹ
abẹ́rẹ; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.
30 Nwọn si ṣe awo adé mimọ́ na ni kìki
wurà, nwọn si kọwe si i, ikọwe bi fifin èdidi-
àmi, MIMỌ SI OLUWA.
31 Nwọn si dì ọjá àwọn alaró mọ́ ọ, lati
fi dì i loke sara fila na; bi OLUWA ti paṣẹ
fun Mose.
32 Bẽni gbogbo iṣẹ agọ́ ti agọ́ ajọ na
pari: awọn ọmọ Israeli si ṣe gẹgẹ bi gbo-
gbo eyiti OLUWA palaṣẹ fun Mose, bẽni
nwọn ṣe.
33 Nwọn si mú agọ́ na tọ̀ Mose wá, agọ́
na, ati gbogbo ohunèlo rẹ̀, ikọ́ rẹ̀, apáko
rẹ̀, ọpá rẹ̀, ati ọwọ̀n rẹ̀, ati ihò-ìtẹbọ rẹ̀
wọnni;
34 Ati ibori awọ àgbo ti a sè ni pupa,
ati ibori awọ seali, ati ikele aṣọ-tita.
35 Apoti ẹrí nì, ati ọpá rẹ̀ wọnni, ati
itẹ́-ãnu nì;
36 Tabili na, ati gbogbo ohunèlo rẹ̀, ati
àkara ifihàn;
37 Ọpá-fitila mimọ́, pẹlu fitila rẹ̀ wọnni,
fitila ti a tò li ẹsẹ̀-ẹsẹ̀, ati gbogbo ohun-èlo
rẹ̀, ati oróro titanna;
38 Ati pẹpẹ wurà, ati oróro itasori, ati
turari didùn, ati aṣọ-isorọ̀ fun ẹnu-ọ̀na agọ́
na;
39 Pẹpẹ idẹ, ati oju-àro-àwọn idẹ rẹ̀,
ọpá rẹ̀, ati gbogbo ohunèlo rẹ̀, agbada na
ati ẹsẹ̀ rẹ̀;
40 Aṣọ-tita agbalá na, ọwọ̀n rẹ̀ ati ihò-
ìtẹbọ rẹ̀, ati aṣọ-isorọ̀ ẹnu-ọ̀na agbalá na,
okùn rẹ̀, ati ekàn rẹ̀, ati gbogbo ohunèlo
ìsin agọ́ na, ani agọ́ ajọ;
41 Aṣọ ìsin lati ma fi sìn ninu ibi mimọ́,
ati aṣọ mimọ́ wọnni fun Aaroni alufa, ati
aṣọ awọn ọmọ rẹ̀, lati ma fi ṣe iṣẹ alufa.
42 Gẹgẹ bi gbogbo ohun ti OLUWA fi
aṣẹ fun Mose, bẽli awọn ọmọ Israeli ṣe
gbogbo iṣẹ na.
43 Mose si bojuwò gbogbo iṣẹ na, si
kiyesi i, nwọn si ṣe e bi OLUWA ti palaṣẹ,
bẽ gẹgẹ ni nwọn ṣe e; Mose si sure fun
wọn.

## ORI 40.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Li ọjọ́ kini oṣù kini ni ki iwọ ki o
gbé ibugbé agọ́ na ró.
3 Iwọ o si fi apoti ẹrí nì sinu rẹ̀, iwọ o si
ta aṣọ-ikele nì bò apoti na.
4 Iwọ o si gbé tabili wọle, ki o si tò
ohun wọnni ti o ni itò si ori rẹ̀; iwọ o si
mú ọpá-fitila wọle, iwọ o si tò fitila rẹ̀
wọnni lori rẹ̀.
5 Iwọ o si fi pẹpẹ wurà ti turari nì si
iwaju apoti ẹrí, iwọ o si fi aṣọ-isorọ̀ ẹnu-
ọ̀na sara agọ́ na.
6 Iwọ o si fi pẹpẹ ẹbọsisun nì si iwaju
ẹnu-ọ̀na ibugbé agọ́ ajọ.
7 Iwọ o si gbé agbada nì kà agbedemeji
agọ́ ajọ ati pẹpẹ, iwọ o si pọn omi sinu rẹ̀.
8 Iwọ o si fà agbalá na yiká, iwọ o si ta
aṣọ-isorọ̀ si ẹnu-ọ̀na agbalá na.
9 Iwọ o si mú oróro itasori nì, iwọ o si
ta a sara agọ́ na, ati sara ohun gbogbo ti o
wà ninu rẹ̀, iwọ o si yà a simimọ́, ati gbo-
gbo ohun-èlo rẹ̀: yio si jẹ́ mimọ́.
10 Iwọ o si ta oróro sara pẹpẹ ẹbọsisun,
ati gbogbo ohun-èlo rẹ̀, iwọ o si yà pẹpẹ na
simimọ́: yio si ma jẹ́ pẹpẹ ti o mọ́ julọ.
11 Iwọ o si ta oróro sara agbada ati ẹsẹ̀
rẹ̀, iwọ o si yà a simimọ́.
12 Iwọ o si mú Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀
wá si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, iwọ o si fi omi wẹ̀
wọn.
13 Iwọ o si fi aṣọ mimọ́ wọnni wọ̀ Aaro-
ni; iwọ o si ta oróro si i li ori, iwọ o si

Digitized by Google

yà a simimọ́, ki o le ma ṣe iṣẹ alufa fun
mi.
14 Iwọ o si mú awọn ọmọ rẹ̀ wá, iwọ o si
fi ẹ̀wu wọ̀ wọn :
15 Iwọ o si ta oróro si wọn li ori, bi iwọ
ti ta si baba wọn li ori, ki nwọn ko le ma
ṣe iṣẹ alufa fun mi : nitoriti itasori wọn yio
jẹ́ iṣẹ-alufa lailai nitõtọ, lati irandiran wọn.
16 Bẽni Mose ṣe : gẹgẹ bi eyiti OLUWA
palaṣẹ fun u, bẽli o ṣe.
17 O si ṣe li oṣù kini li ọdún keji ni ijọ́
kini oṣù na, ni a gbé agọ́ na ró.
18 Mose si gbé agọ́ na ró, o si de ihò-
ìtẹbọ rẹ̀, o si tò apáko rẹ̀, o si fi ọpá rẹ̀ bọ̀
ọ, o si gbé ọwọ̀n rẹ̀ ró.
19 O si nà aṣọ agọ́ na sori agọ́, o si fi
ibori agọ́ na bò o li ori ; bi OLUWA ti paṣẹ
fun Mose.
20 O si mú, o si fi ẹrí nì sinu apoti na,
o si fi ọpá wọnni sara apoti na, o si fi itẹ́-
ãnu nì si oke lori apoti na :
21 O si gbé apoti na wá sinu agọ́, o si ta
aṣọ-ikele, o si ta a bò apoti ẹrí ; bi OLUWA
ti paṣẹ fun Mose.
22 O si fi tabili nì sinu agọ́ ajọ, ni ìha
ariwa agọ́ na, lẹhin ode aṣọ-ikele nì.
23 O si tò àkara na lẹ̀sẹsẹ daradara lori
rẹ̀ niwaju OLUWA ; bi OLUWA ti paṣẹ fun
Mose.
24 O si fi ọpá-fitila nì sinu agọ́ ajọ, ki o
kọjusi tabili nì ni ìha gusù agọ na.
25 O si tàn fitila wọnni siwaju OLUWA ;
bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose.
26 O si fi pẹpẹ wurà nì sinu agọ́ ajọ ni-
waju aṣọ-ikele nì :
27 O si fi turari didùn joná lori rẹ̀ ; bi
OLUWA ti paṣẹ fun Mose.
28 O si ta aṣọ-isorò nì si ẹnu-ọ̀na agọ́
na.
29 O si fi pẹpẹ ẹbọsisun si ẹnu-ọ̀na ibu-
gbé agọ́ ajọ, o si ru ẹbọ sisun, ati ẹbọ
ohunjijẹ lori rẹ̀ ; bi OLUWA ti paṣẹ fun
Mose.
30 O si gbé agbada nì kà agbedemeji agọ́
ajọ ati pẹpẹ, o si pọn omi si i, lati ma fi
wẹ̀.
31 Ati Mose ati Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀
wẹ̀ ọwọ́ ati ẹsẹ̀ wọn ninu rẹ̀.
32 Nigbati nwọn ba lọ sinu agọ́ ajọ, ati
nigbati nwọn ba sunmọ pẹpẹ na, nwọn a
wẹ̀ ; bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose.
33 O si fà agbalá na yi agọ́ ati pẹpẹ na
ká, o si ta aṣọ-isorò ẹnu-ọ̀na agbalá na.
Bẽni Mose pari iṣẹ na.
34 Nigbana li awọsanma bò agọ́ ajọ, ogo
OLUWA si kún inu agọ́ na.
35 Mose kò si le wọ̀ inu agọ́ ajọ lọ, ni-
toriti awọsanma wà lori rẹ̀, ogo OLUWA si
kun inu agọ́ na.
36 Nigbati a si fà awọsanma na soke,
kuro lori agọ́ na, awọn ọmọ Israeli a ma
dide rìn lọ ni ìrin wọn gbogbo :
37 Ṣugbọn bi a kò fà awọsanma na soke,
njẹ nwọn kò ni idide rìn titi ọjọkọjọ́ ti o ba
fà soke.
38 Nitoriti awọsanma OLUWA wà lori
agọ́ na li ọsán, iná si wà ninu awọsanma na
li oru, li oju gbogbo ile Israeli, ni gbogbo
ìrin wọn.

---

IWE KẸTA MOSE

TI A NPE NI

# LEFITIKU.

## ORI 1.

OLUWA si pè Mose, o si sọ fun u lati inu
agọ́ ajọ wá, pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Bi ẹnikan ninu nyin ba mú
ọrẹ-ẹbọ wá fun OLUWA, ki ẹnyin ki o mú
ọrẹ-ẹbọ nyin wá ninu ohunọ̀sin, ani ti inu
ọwọ́-ẹran, ati ti agbo-ẹran.
3 Bi ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ ba ṣe ẹbọ sisun ti inu
ọwọ́-ẹran, ki on ki o mú akọ wá alailabùku :
ki o mú u wá tinutinu rẹ̀ si ẹnu-ọ̀na agọ́
ajọ siwaju OLUWA.
4 Ki o si fi ọwọ rẹ̀ lé ori ẹbọ sisun

Digitized by Google

na; yio si di itẹwọgbà fun u lati ṣètutu
fun u.
5 Ki o si pa akọmalu na niwaju OLUWA:
awọn alufa, awọn ọmọ Aaroni, yio si mú
ẹ̀jẹ na wá, nwọn o si fi ẹ̀jẹ na wọ́n ori pẹpẹ
nì yiká ti mbẹ li ẹnu-ọ̀na-agọ́ ajọ.
6 Ki o si họ ẹbọ sisun na; ki o si kun u.
7 Awọn ọmọ Aaroni alufa ni yio si fi iná
sori pẹpẹ na, nwọn o si tò igi lori iná na:
8 Awọn alufa, awọn ọmọ Aaroni yio si
tò ninu rẹ̀, ani ori ati ọrá wọn sori igi ti
mbẹ lori iná, ti mbẹ lori pẹpẹ:
9 Ṣugbọn ifun rẹ̀, ati itan rẹ̀ ni ki o ṣìn
ninu omi: ki alufa ki o si sun gbogbo rẹ̀,
lori pẹpẹ na, lati ṣe ẹbọ sisun, ẹbọ ti a fi
iná ṣe, õrùn didùn si OLUWA.
10 Bi ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ ba si ṣe ti agbo-ẹran,
eyinì ni ti agutan, tabi ti ewurẹ, fun ẹbọ
sisun; akọ ni ki o múwa alailabùku.
11 Ki o si pa a niwaju OLUWA li ẹba
pẹpẹ ni ìha ariwa: ati awọn alufa, awọn
ọmọ Aaroni yio si bù ẹ̀jẹ rẹ̀ wọn ori pẹpẹ
na yiká.
12 Ki o si kun u, ori rẹ̀ ati ọrá rẹ̀:
alufa na yio si tò wọn sori igi ti mbẹ lori
iná ti mbẹ lori pẹpẹ:
13 Ṣugbọn ki o ṣìn ifun ati itan rẹ̀ ninu
omi: ki alufa na ki o si mú gbogbo rẹ̀ wá,
ki o si sun u lori pẹpẹ: ẹbọ sisun ni, ẹbọ
ti a fi iná ṣe, õrùn didùn si OLUWA.
14 Bi o ba si ṣepe ti ẹiyẹ ni ẹbọ sisun
ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ si OLUWA, njẹ ki o mú ọrẹ-ẹbọ
rẹ̀ wá ninu àdaba, tabi ninu ọmọ ẹiyẹle.
15 Ki alufa na ki o si mú u wá si pẹpẹ
na, ki o si mi i li ọrùn, ki o si sun u lori
pẹpẹ na; ẹ̀jẹ rẹ̀ ni ki o si ro si ẹba pẹpẹ na.
16 Ki o si fà ajẹsi rẹ̀ já pẹlu ẽri rẹ̀, ki o
si kó o lọ si ẹba pẹpẹ na ni ìha ìla-õrùn,
lori ibi eru nì:
17 Ki o si là a ti on ti iyẹ́-apa rẹ̀, ṣu-
gbọn ki yio pín i ni meji jalẹ: ki alufa ki o
si sun u lori pẹpẹ na, lori igi na ti mbẹ lori
iná: ẹbọ sisun ni, ẹbọ ti a fi iná ṣe, õrùn
didùn si OLUWA.

## ORI 2.

NIGBATI ẹnikan ba si nta ọrẹ-ẹbọ ohun-
jijẹ fun OLUWA, ki ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ ki o jẹ
ti iyẹfun daradara; ki o si dà oróro sori rẹ̀,
ki o si fi turari sori rẹ̀.
2 Ki o si mú u tọ̀ awọn alufa, awọn
ọmọ Aaroni wá: ki alufa si bù ikunwọ kan
ninu rẹ̀, ninu iyẹfun na, ati ninu oróro na,
pẹlu gbogbo turari rẹ̀; ki o si sun ẹbọ-
iranti rẹ̀ lori pẹpẹ, lati ṣe ẹbọ ti a fi iná ṣe,
õrùn didùn si OLUWA:
3 Iyokù ti ẹbọ ohunjijẹ na, a si jẹ ti
Aaroni, ati ti awọn ọmọ rẹ̀: ohun mimọ́
julọ lati inu ẹbọ OLUWA ni ti a fi iná ṣe.
4 Bi iwọ ba si mú ọrẹ-ẹbọ ohunjijẹ wá, ti
a yan ninu àro, ki o jẹ́ àkara alaiwu iyẹfun
didara, ti a fi oróro pò, tabi àkara fẹlẹfẹlẹ
alaiwu ti a ta oróro si.
5 Ati bi ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ ba ṣe ohunjijẹ, ti a ṣe
ninu awopẹtẹ, ki o jẹ́ ti iyẹfun didara
alaiwu, ti a fi oróro pò.
6 Ki iwọ ki o si dá a kelekele, ki o si dà
oróro sori rẹ̀: ẹbọ ohunjijẹ ni.
7 Ati bi ọrẹ-ẹbọ rẹ ba ṣe ẹbọ ohunjijẹ, ti
a yan ninu apẹ, iyẹfun didara ni ki a fi ṣe
e pẹlu oróro.
8 Ki iwọ ki o si mú ẹbọ ohunjijẹ na wá,
ti a fi nkan wọnyi ṣe fun OLUWA: on o si
mú u tọ̀ alufa na wá, ki on ki o si mú u wá
sori pẹpẹ nì.
9 Alufa yio si mú ẹbọ-iranti ninu ohun-
jijẹ na, yio si sun u lori pẹpẹ: ẹbọ ti a fi
iná ṣe, õrùn didùn si OLUWA.
10 Eyiti o si kù ninu ẹbọ ohunjijẹ, ki o
jẹ́ ti Aaroni, ati ti awọn ọmọ rẹ̀: ohun
mimọ́ julọ ni, ọrẹ-ẹbọ OLUWA ti a fi iná ṣe.
11 A kò gbọdọ fi iwukàra ṣe gbogbo ẹbọ
ohunjijẹ ti ẹnyin o mú tọ̀ OLUWA wá:
nitori ẹnyin kò gbọdọ sun iwukàra, tabi
oyinkoyin, ninu ọrẹ-ẹbọ OLUWA, ti a fi
iná ṣe.
12 Bi ọrẹ-ẹbọ akọ́so, ẹnyin le mú wọn
wá fun OLUWA: ṣugbọn a ki yio sun wọn
lori pẹpẹ fun õrùn didùn.
13 Ati gbogbo ọrẹ-ẹbọ ohunjijẹ rẹ ni ki
iwọ ki o fi iyọ̀ dùn; bẹ̃ni iwọ kò gbọdọ jẹ
ki iyọ̀ majẹmu Ọlọrun rẹ ki o má si ninu
ẹbọ ohunjijẹ rẹ: gbogbo ọrẹ-ẹbọ rẹ ni ki
iwọ ki o fi iyọ̀ si.
14 Bi iwọ ba si mú ẹbọ ohunjijẹ akọ́so rẹ
wá fun OLUWA, ki iwọ ki o si mú ṣiri ọkà
daradara ti a yan lori iná wá fun ẹbọ ohun-
jijẹ akọ́so rẹ, ọkà gigún, ti ṣiri tutù.
15 Ki iwọ ki o si fi oróro sori rẹ̀, ki o si
fi turari sori rẹ̀: ẹbọ ohunjijẹ ni.
16 Ki alufa ki o si sun ẹbọ-iranti rẹ̀,
apakan ninu ọkà gigún rẹ̀, ati apakan ninu
oróro rẹ̀, pẹlu gbogbo turari rẹ̀: ẹbọ ti a fi
iná ṣe ni si OLUWA.

## ORI 3.

BI ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ ba si ṣe ẹbọ alafia, bi o ba mú
u lati inu ọwọ́-ẹran wá, on iba ṣe akọ
tabi abo, ki o mú u wá siwaju OLUWA li
ailabùku.
2 Ki o si fi ọwọ́ rẹ̀ lé ori ọrẹ-ẹbọ rẹ̀, ki o
si pa a li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ: ki awọn alufa,

Digitized by Google

awọn ọmọ Aaroni ki o si fi ẹ̀jẹ na wọ́n ori
pẹpẹ nì yiká.
3 Ki o si mú ninu ẹbọ alafia nì wá, ọrẹ-
ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA; ọrá ti o bò
ifun lori, ati gbogbo ọrá ti mbẹ lara ifun na.
4 Ati iwe nì mejeji, ati ọrá ti mbẹ lara
wọn, ti mbẹ li ẹba ìha, ati àwọn ti o bò
ẹ̀dọ, pẹlu iwe nì, on ni ki o mú kuro.
5 Ki awọn ọmọ Aaroni ki o si sun u lori
pẹpẹ nì lori ẹbọ sisun, ti mbẹ lori igi ti o
wà lori iná: ẹbọ ti a fi iná ṣe ni, õrùn
didùn si OLUWA.
6 Bi ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ fun ọrẹ-ẹbọ alafia si
OLUWA ba ṣe ti agbo-ẹran; akọ tabi abo,
ki o mú u wá li ailabùku.
7 Bi o ba mu ọdọ-agutan wá fun ọrẹ-ẹbọ
rẹ̀, njẹ ki o mú u wá siwaju OLUWA:
8 Ki o si fi ọwọ́ rẹ̀ lé ori ọrẹ-ẹbọ rẹ̀, ki o
si pa a niwaju agọ́ ajọ: ki awọn ọmọ
Aaroni ki o si fi ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ wọ́n ori pẹpẹ na
yiká.
9 Ki o si múwa ninu ẹbọ alafia nì, ẹbọ ti
a fi iná ṣe si OLUWA; ọrá rẹ̀, ati gbogbo
ìru rẹ̀ ti o lọrá, on ni ki o mú kuro sunmọ
egungun ẹhin; ati ọrá ti o bò ifun lori, ati
gbogbo ọrá ti mbẹ lara ifun,
10 Ati iwe mejeji, ati ọrá ti mbẹ lara
wọn, ti mbẹ lẹba ìha, ati àwọn ti o bò ẹ̀dọ,
pẹlu iwe nì, on ni ki o mú kuro.
11 Ki alufa ki o si sun u lori pẹpẹ: onjẹ
ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA ni.
12 Bi ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ ba si ṣe ewurẹ, njẹ ki o
mú u wá siwaju OLUWA:
13 Ki o si fi ọwọ́ rẹ̀ lé ori rẹ̀, ki o si pa a
niwaju agọ́ ajọ: ki awọn ọmọ Aaroni ki o
si fi ẹ̀jẹ rẹ̀ wọ́n ori pẹpẹ na yiká.
14 Ki o si mú ninu ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ wá, ani
ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA; ọrá ti o bò
ifun lori, ati gbogbo ọrá ti o mbẹ lara ifun.
15 Ati iwe nì mejeji, ati ọrá ti mbẹ lara
wọn, ti mbẹ lẹba ìha, ati àwọn ti o bò ẹ̀dọ,
pẹlu iwe nì, on ni ki o mú kuro.
16 Ki alufa ki o si sun wọn lori pẹpẹ:
onjẹ ẹbọ ti a fi iná ṣe fun õrùn didùn ni:
ti OLUWA ni gbogbo ọrá.
17 Ilana titilai ni fun irandiran nyin, ni
gbogbo ibugbé nyin, pe ki ẹnyin ki o máṣe
jẹ ọrá tabi ẹ̀jẹ.

## ORI 4.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Bi
ọkàn kan ba fi aimọ̀ ṣẹ̀ si ọkan ninu ofin
OLUWA, li ohun ti kò yẹ ni ṣiṣe, ti o si ṣẹ̀
si ọkan ninu wọn:
3 Bi alufa ti a fi oróro yàn ba ṣẹ̀ gẹgẹ bi
ẹ̀ṣẹ awọn enia; nigbana ni ki o mú ẹgbọrọ
akọmalu kan alailabùku fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ wá
fun OLUWA nitori ẹ̀ṣẹ ti o ti ṣẹ̀.
4 Ki o si mú akọmalu na wá si ẹnu-ọ̀na
agọ́ ajọ niwaju OLUWA; ki o si fi ọwọ́ rẹ̀
lé ori akọmalu na, ki o si pa akọmalu na
niwaju OLUWA.
5 Ki alufa na ti a fi oróro yàn, ki o bù
ninu ẹ̀jẹ akọmalu na, ki o si mú u wá si
agọ́ ajọ:
6 Ki alufa na ki o tẹ̀ ika rẹ̀ bọ̀ inu ẹ̀jẹ
na, ki o si fi ninu ẹ̀jẹ na wọ́n nkan nigba
meje niwaju OLUWA, niwaju aṣọ-ikele ibi
mimọ́.
7 Ki alufa ki o si fi diẹ ninu ẹ̀jẹ na sara
iwo pẹpẹ turari didùn niwaju OLUWA, eyiti
mbẹ ninu agọ́ ajọ; ki o si dà gbogbo ẹ̀jẹ
akọmalu nì si isalẹ pẹpẹ ẹbọsisun, ti mbẹ li
ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ.
8 Ki o si mú gbogbo ọrá akọmalu nì fun
ẹbọ ẹ̀ṣẹ kuro lara rẹ̀; ọrá ti o bò ifun lori,
ati gbogbo ọrá ti mbẹ lara ifun na,
9 Ati iwe mejeji, ati ọrá ti mbẹ lara
wọn, ti mbẹ lẹba ìha, ati àwọn ti o bò ẹ̀dọ,
pẹlu iwe, on ni ki o mu kuro,
10 Bi a ti mú u kuro lara akọmalu ẹbọ-
ọrẹ ẹbọ alafia: ki alufa ki o si sun wọn lori
pẹpẹ ẹbọsisun.
11 Ati awọ akọmalu na, ati gbogbo ẹran
rẹ̀, pẹlu ori rẹ̀, ati pẹlu itan rẹ̀, ati ifun rẹ̀,
ati igbẹ́ rẹ̀,
12 Ani gbogbo akọmalu na ni ki o mú
jade lọ sẹhin ibudó si ibi mimọ́ kan, ni ibi
ti a ndà ẽru si, ki o si fi iná sun u lori igi:
ni ibi ti a ndà ẽru si ni ki a sun u.
13 Bi gbogbo ijọ enia Israeli ba si fi
aimọ̀ ṣẹ̀, ti ohun na si pamọ́ li oju ijọ, ti
nwọn si ṣì ohun kan ṣe si ọkan ninu ofin
OLUWA, ti a ki ba ṣe, ti nwọn si jẹbi;
14 Nigbati ẹ̀ṣẹ ti nwọn ba ti ṣẹ̀ si i, ba
di mimọ̀, nigbana ni ki ijọ enia ki o mú
ẹgbọrọ akọmalu kan wá nitori ẹ̀ṣẹ na, ki
nwọn ki o si mú u wá siwaju agọ́ ajọ.
15 Ki awọn àgbagba ijọ enia ki o fi ọwọ́
wọn lé ori akọmalu na niwaju OLUWA: ki
a si pa akọmalu na niwaju OLUWA.
16 Ki alufa ti a fi oróro yàn ki o si mú
ninu ẹ̀jẹ akọmalu na wá si agọ́ ajọ:
17 Ki alufa na ki o si tẹ̀ ika rẹ̀ bọ̀ inu
ẹ̀jẹ na, ki o si wọ́n ọ nigba meje niwaju
OLUWA, niwaju aṣọ-ikele.
18 Ki o si fi diẹ ninu ẹ̀jẹ na sara iwo
pẹpẹ ti mbẹ niwaju OLUWA, ti mbẹ ninu
agọ́, ki o si dà gbogbo ẹ̀jẹ na si isalẹ pẹpẹ
ẹbọsisun, ti mbẹ li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ.

Digitized by Google

19 Ki o si mú gbogbo ọrá rẹ̀ lara rẹ̀, ki o si sun u lori pẹpẹ.

20 Ki o si fi akọmalu na ṣe; bi o ti fi akọmalu ẹbọ ẹ̀ṣẹ ṣe, bẽni ki o si fi eyi ṣe: ki alufa na ki o si ṣètutu fun wọn, a o si dari rẹ̀ jì wọn.

21 Ki o si gbé akọmalu na jade lọ sẹhin ibudó, ki o si sun u bi o ti sun akọmalu iṣaju: ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni fun ijọ enia.

22 Nigbati ijoye kan ba ṣẹ̀, ti o si fi aimọ̀ rú ọkan ninu ofin OLUWA Ọlọrun rẹ̀, ti a ki ba rú, ti o si jẹbi;

23 Tabi bi ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ninu eyiti o ti ṣẹ̀, ba di mimọ̀ fun u; ki o mú ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ wá, ọmọ ewurẹ kan, akọ alailabùku:

24 Ki o si fi ọwọ́ rẹ̀ lé ori ewurẹ na, ki o si pa a ni ibiti nwọn gbé npa ẹbọ sisun niwaju OLUWA: ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni.

25 Ki alufa na ki o si fi ika rẹ̀ mú ninu ẹ̀jẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ na, ki o si fi i sara iwo pẹpẹ ẹbọsisun, ki o si dà ẹ̀jẹ si isalẹ pẹpẹ ẹbọsisun.

26 Ki o si sun gbogbo ọrá rẹ̀ li ori pẹpẹ, bi ti ọrá ẹbọ alafia: ki alufa ki o si ṣètutu fun u nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀, a o si dari rẹ̀ jì i.

27 Bi ọkan ninu awọn enia ilẹ na ba fi aimọ̀ ṣẹ̀, nigbati o ba ṣì ohun kan ṣe si ọkan ninu ofin OLUWA ti a ki ba ṣe, ti o si jẹbi;

28 Tabi bi ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ti o ti ṣẹ̀, ba di mimọ̀ fun u, nigbana ni ki o mú ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ wá, ọmọ ewurẹ kan, abo alailabùku, nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ti ṣẹ̀.

29 Ki o si fi ọwọ́ rẹ̀ lé ori ẹbọ ẹ̀ṣẹ na, ki o si pa ẹbọ ẹ̀ṣẹ na ni ibi ẹbọsisun.

30 Ki alufa ki o si fi ika rẹ̀ mú ninu ẹ̀jẹ na, ki o si fi i sara iwo pẹpẹ ẹbọsisun, ki o si dà gbogbo ẹ̀jẹ rẹ̀ si isalẹ pẹpẹ.

31 Ki o si mú gbogbo ọrá rẹ̀ kuro, bi a ti imú ọrá kuro ninu ẹbọ ọrẹ-ẹbọ alafia; ki alufa ki o si sun u lori pẹpẹ, fun õrùn didùn si OLUWA; ki alufa na ki o si ṣètutu fun u, a o si dari rẹ̀ jì i.

32 Bi o ba si mú ọdọ-agutan kan wá fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ki o si mú u wá, abo alailabùku.

33 Ki o si fi ọwọ́ rẹ̀ lé ori ẹbọ ẹ̀ṣẹ na, ki o si pa a fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni ibi ti nwọn gbé npa ẹbọ sisun.

34 Ki alufa ki o si fi ika rẹ̀ mú ninu ẹ̀jẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ na, ki o si fi i sara iwo pẹpẹ ẹbọsisun, ki o si dà gbogbo ẹ̀jẹ rẹ̀ si isalẹ pẹpẹ:

35 Ki o si mú gbogbo ọrá rẹ̀ kuro, bi a ti imú ọrá ọdọ-agutan kuro ninu ẹbọ ọrẹ-ẹbọ alafia; ki alufa ki o si sun wọn lori pẹpẹ, gẹgẹ bi ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA: ki alufa ki o si ṣètutu fun ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ti ṣẹ̀, a o si dari rẹ̀ jì i.

## ORI 5.

BI ẹnikan ba si ṣẹ̀, ti o si gbọ́ ohùn ibura, ti o si ṣe ẹlẹri, bi on ba ri tabi bi on ba mọ̀, ti kò ba wi, njẹ ki o rù aiṣedede rẹ̀.

2 Tabi bi ẹnikan ba farakàn ohun alaimọ́ kan, iba ṣe okú ẹranko alaimọ, tabi okú ẹranọ̀sin alaimọ́, tabi okú ohun ti nrakò alaimọ́, ti o ba si pamọ́ fun u, on pẹlu yio si ṣe alaimọ́, yio si jẹbi:

3 Tabi bi o ba farakàn ohun aimọ́ ti enia, ohunkohun aimọ́ ti o wù ki o ṣe ti a fi sọ enia di elẽri, ti o ba si pamọ́ fun u; nigbati o ba mọ̀, nigbana ni on o jẹbi:

4 Tabi bi ẹnikan ba bura, ti o nfi ète rẹ̀ sọ ati ṣe ibi, tabi ati ṣe rere, ohunkohun ti o wù ki o ṣe ti enia ba fi ibura sọ, ti o ba si pamọ́ fun u; nigbati o ba mọ̀, nigbana ni on o jẹbi ọkan ninu ohun wọnyi:

5 Yio si ṣe, nigbati o ba jẹbi ọkan ninu ohun wọnyi, ki o jẹwọ pe on ti ṣẹ̀ li ohun na.

6 Ki o si mú ẹbọ ẹbi rẹ̀ wá fun OLUWA, nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ti ṣẹ̀, abo lati inu agboẹran wá, ọdọ-agutan tabi ọmọ ewurẹ kan, fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; ki alufa ki o si ṣètutu fun u nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀.

7 Bi kò ba si le mú ọdọ-agutan wá, njẹ ki o mú àdaba meji tabi ọmọ ẹiyẹle meji wá fun ẹbọ ẹbi fun OLUWA nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ti o ti ṣẹ̀; ọkan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ekeji fun ẹbọ sisun.

8 Ki o si mú wọn tọ alufa wá, ẹniti yio tète rubọ eyiti iṣe ti ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ti yio si mi i li ọrùn, ṣugbọn ki yio pín i meji:

9 Ki o si fi ninu ẹ̀jẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ nì wọ́n ìha pẹpẹ; ati ẹ̀jẹ iyokù ni ki a ro si isalẹ pẹpẹ na: ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni.

10 Ki o si ru ekeji li ẹbọ sisun, gẹgẹ bi ìlana na: ki alufa ki o si ṣètutu fun u, nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ti ṣẹ̀, a o si dari rẹ̀ jì i.

11 Ṣugbọn bi on kò ba le mú àdaba meji, tabi ọmọ ẹiyẹle meji wá, njẹ ki ẹniti o ṣẹ̀ na ki o mú idamẹwa òṣuwọn efa iyẹfun daradara wá fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; ki o máṣe fi oróro si i, bẽni ki o máṣe fi turari sori rẹ̀: nitoripe ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni.

12 Nigbana ni ki o mú u tọ̀ alufa wá, ki alufa ki o si bù ikunwọ rẹ̀ kan ninu rẹ̀, ani ẹbọ-iranti rẹ, ki o si sun u lori pẹpẹ na, gẹgẹ bi ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA: ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni.

13 Ki alufa ki o si ṣètutu fun u nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ti ṣẹ̀ li ọkan ninu wọnyi, a o si dara rẹ̀ jì i: iyokù si jẹ́ ti alufa, bi ẹbọ ohunjijẹ.

Digitized by Google

14 OLUWA si sọ fun Mose pe,

15 Bi ẹnikan ba ṣìṣe, ti o ba si fi aimọ̀ ṣẹ̀ ninu ohun mimọ́ OLUWA; nigbana ni ki o múwa fun OLUWA nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀, àgbo kan alailabùku lati inu agbo-ẹran wá, ni idiyele rẹ nipa ṣekeli fadakà, gẹgẹ bi ṣekeli ibi mimọ́ fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ.

16 Ki o si ṣe atunṣe nitori ibi ti o ti ṣe ninu ohun mimọ́, ki o si fi idamarun pẹlu rẹ̀, ki o si fi i fun alufa: alufa yio si fi àgbo ẹbọ ẹ̀ṣẹ na ṣètutu fun u, a o si dari rẹ̀ jì i.

17 Bi ẹnikan ba si ṣẹ̀, ti o ba si ṣe ọkan ninu nkan wọnyi, eyiti ofin OLUWA kọ̀ lati ṣe; bi kò tilẹ mọ̀, ṣugbọn o jẹbi, yio si rù ẹ̀ṣẹ rẹ̀.

18 Ki o si mú àgbo kan alailabùku lati inu agbo-ẹran tọ̀ alufa wá ni idiyele rẹ, fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ: ki alufa ki o si ṣètutu fun u nitori aimọ̀ rẹ̀ ninu eyiti o ṣìṣe ti kò si mọ̀, a o si dari rẹ̀ jì i.

19 Ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni: nitõtọ li o dẹ̀ṣẹ si OLUWA.

## ORI 6.

OLUWA si sọ fun Mose pe,

2 Bi ẹnikan ba ṣẹ̀, ti o dẹ̀ṣẹ si OLUWA, ti o si sẹ́ fun ẹnikeji rẹ̀, li ohun ti o fi fun u pamọ́, tabi li ohun ti a fi dógo, tabi ohun ti a fi agbara gbà, tabi ti o rẹ ẹnikeji rẹ̀ jẹ;

3 Tabi ti o ri ohun ti o nù he, ti o si ṣeké nitori rẹ̀, ti o si bura eké; li ọkan ninu gbogbo ohun ti enia ṣe, ti o ṣẹ̀ ninu rẹ̀:

4 Yio si ṣe, bi o ba ti ṣẹ̀, ti o si jẹbi, ki o si mú ohun ti o fi agbara gbà pada, tabi ohun ti o fi irẹjẹ ní, tabi ohun ti a fi fun u pamọ́, tabi ohun ti o nù ti o rihe.

5 Tabi gbogbo eyi na nipa eyiti o bura eké; ki o tilẹ mú u pada li oju-owo rẹ̀, ki o si fi idamarun rẹ̀ lé ori rẹ̀, ki o si fi i fun olohun, li ọjọ́ ẹbọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀.

6 Ki o si mú ẹbọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ wá fun OLUWA, àgbo kan alailabùku lati inu agbo-ẹran tọ̀ alufa wá, ni idiyele rẹ fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ:

7 Alufa yio si ṣètutu fun u niwaju OLUWA, a o si dari rẹ̀ jì; nitori ohunkohun ninu gbogbo ohun eyiti o ti ṣe ti o si jẹbi ninu rẹ̀.

8 OLUWA si sọ fun Mose pe,

9 Paṣẹ fun Aaroni ati fun awọn ọmọ rẹ̀ pe, Eyi li ofin ẹbọ sisun: Ẹbọ sisun ni, nitori sisun rẹ̀ lori pẹpẹ ni gbogbo oru titi di owurọ̀, iná pẹpẹ na yio si ma jó ninu rẹ̀.

10 Ki alufa ki o si mú ẹ̀wu ọ̀gbọ rẹ̀ wọ̀, ati ṣòkoto ọ̀gbọ rẹ̀ ni ki o fi si ara rẹ̀, ki o si kó ẽru ti iná jọ, ti on ti ẹbọ sisun lori pẹpẹ, ki o si fi i si iha pẹpẹ.

11 Ki o si bọ́ ẹ̀wu rẹ̀ silẹ, ki o si mú ẹ̀wu miran wọ̀, ki o si gbé ẽru wọnni jade lọ sẹhin ibudó si ibi kan ti o mọ́.

12 Ki iná ori pẹpẹ ni ki o si ma jó lori rẹ̀; ki a máṣe pa a; ki alufa ki o si ma kóná igi lori rẹ̀ li orowurọ̀, ki o si tò ẹbọ sisun sori rẹ̀; ki o si ma sun ọrá ẹbọ alafia lori rẹ̀.

13 Ki iná ki o ma jó titi lori pẹpẹ na; kò gbọdọ kú lai.

14 Eyi si li ofin ẹbọ ohunjijẹ: ki awọn ọmọ Aaroni ki o ru u niwaju OLUWA, niwaju pẹpẹ.

15 Ki o si bù ikunwọ rẹ̀ kan ninu rẹ̀, ninu iyẹfun didara ẹbọ ohunjijẹ na, ati ti oróro rẹ̀, ati gbogbo turari ti mbẹ lori ẹbọ ohunjijẹ, ki o si sun u lori pẹpẹ fun õrùn didùn, ani fun iranti rẹ̀, si OLUWA.

16 Iyokù rẹ̀ ni Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ yio jẹ: àkara alaiwu ni, ki a jẹ ẹ ni ibi mimọ́; ni agbalá agọ́ ajọ ni ki nwọn ki o jẹ ẹ.

17 Ki a máṣe fi iwukàra yan a. Mo ti fi i fun wọn ni ipín ti wọn ninu ẹbọ mi ti a fi iná ṣe; mimọ́ julọ ni, bi ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati bi ẹbọ ẹbi.

18 Gbogbo awọn ọkọnrin ninu awọn ọmọ Aaroni ni ki o jẹ ninu rẹ̀, yio jasi aṣẹ titilai ni iraniran nyin, nipa ẹbọ OLUWA ti a fi iná ṣe: ẹnikẹni ti o ba kàn wọn yio di mimọ́.

19 OLUWA si sọ fun Mose pe,

20 Eyi li ọrẹ-ẹbọ Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀, ti nwọn o ru si OLUWA, li ọjọ́ ti a fi oróro yàn a; idamẹwa òṣuwọn efa iyẹfun didara fun ẹbọ ohunjijẹ titilai, àbọ rẹ̀ li owurọ̀, ati àbọ rẹ̀ li alẹ.

21 Ninu awopẹtẹ ni ki a fi oróro ṣe e; nigbati a ba si bọ̀ ọ, ki iwọ ki o si mú u wọ̀ ile: ati ìṣu yiyan ẹbọ ohunjijẹ na ni ki iwọ ki o fi rubọ õrùn didùn si OLUWA.

22 Ati alufa ninu awọn ọmọ rẹ̀ ti a fi oróro yàn ni ipò rẹ̀ ni ki o ru u: aṣẹ titilai ni fun OLUWA, sisun ni ki a sun u patapata.

23 Nitori gbogbo ẹbọ ohunjijẹ alufa, sisun ni ki a sun u patapata: a kò gbọdọ jẹ ẹ.

24 OLUWA si sọ fun Mose pe,

25 Sọ fun Aaroni ati fun awọn ọmọ rẹ̀ pe, Eyi li ofin ẹbọ ẹ̀ṣẹ: ni ibi ti a gbé pa ẹbọ sisun, ni ki a si pa ẹbọ ẹ̀ṣẹ niwaju OLUWA: mimọ́ julọ ni.

26 Alufa ti o ru u fun ẹ̀ṣẹ ni ki o jẹ ẹ: ni ibi mimọ́ kan ni ki a jẹ ẹ, ninu agbalá agọ́ ajọ.

27 Ohunkohun ti o ba kàn ẹran rẹ̀ yio di mimọ́: nigbati ẹ̀jẹ rẹ̀ ba si ta sara aṣọ

Digitized by Google

kan, ki iwọ ki o si fọ̀ eyiti o ta si na ni ibi
mimọ́ kan.
28 Ṣugbọn ohunèlo amọ̀, ninu eyiti a
gbé bọ̀ ọ on ni ki a fọ́; bi a ba si bọ̀ ọ ninu
ìkoko idẹ, ki a si fọ̀ ọ, ki a si ṣìn i ninu
omi.
29 Gbogbo awọn ọkọnrin ninu awọn alufa
ni ki o jẹ ninu rẹ̀: mimọ́ julọ ni.
30 Kò si sí ẹbọ ẹ̀ṣẹ kan, ẹ̀jẹ eyiti a múwa
sinu agọ́ ajọ, lati fi ṣ̀ètutu ni ibi mimọ́, ti
a gbọdọ jẹ: sisun ni ki a sun u ninu iná.

ORI 7.

EYI si li ofin ẹbọ ẹbi: mimọ́ julọ ni.
2 Ni ibi ti nwọn gbé pa ẹbọ sisun
ni ki nwọn ki o pa ẹbọ ẹbi: ki o si fi ẹ̀jẹ rẹ̀
wọ́n ori pẹpẹ yiká.
3 Ki o si fi gbogbo ọrá inu rẹ̀ rubọ; ìru
rẹ̀ ti o lọrá, ati ọrá ti o bò ifun lori,
4 Ati iwe mejeji, ati ọrá ti mbẹ lara
wọn, ti mbẹ lẹba ìha, ati àwọn ti o bò ẹ̀dọ,
pẹlu iwe, on ni ki o mú kuro:
5 Ki alufa ki o si sun wọn lori pẹpẹ, ẹbọ
ti a fi iná ṣe si OLUWA: ẹbọ ẹbi ni.
6 Gbogbo ọkọnrin ninu awọn alufa ni ki
o jẹ ninu rẹ̀: ni ibi mimọ́ kan ni ki a jẹ
ẹ: mimọ́ julọ ni.
7 Bi ẹbọ ẹ̀ṣẹ, bẽ si li ẹbọ ẹbi: ofin kan
ni fun wọn: alufa ti nfi i ṣ̀ètutu ni ki o
ní i.
8 Ati alufa ti nru ẹbọ sisun ẹnikẹni, ani
alufa na ni yio ní awọ ẹran ẹbọ sisun, ti o
ru fun ara rẹ̀.
9 Ati gbogbo ẹbọ ohunjijẹ ti a yan ninu
àro, ati gbogbo eyiti a yan ninu apẹ, ati
ninu awopẹtẹ, ni ki o jẹ́ ti alufa ti o ru u.
10 Ati gbogbo ẹbọ ohunjijẹ ti a fi oróro
pò, ati gbigbẹ, ni ki gbogbo awọn ọmọ
Aaroni ki o ní, ẹnikan bi ẹnikeji rẹ̀.
11 Eyi si ni ofin ẹbọ alafia, ti on o ru si
OLUWA.
12 Bi o ba mú u wá fun idupẹ́, njẹ ki o
mú adidùn àkara alaiwu wá ti a fi oróro
pò, pẹlu ẹbọ ọpẹ́ rẹ̀, ati àkara fẹlẹfẹlẹ alaiwu
ti a ta oróro si, ati adidùn àkara iyẹfun
didara, ti a fi oróro pò, ti a din.
13 Pẹlu adidùn àkara wiwu ki o mú ọrẹ-
ẹbọ pẹlu ẹbọ alafia rẹ̀ wa fun idupẹ́.
14 Ati ninu rẹ̀ ni ki o mú ọkan kuro
ninu gbogbo ọrẹ-ẹbọ na fun ẹbọ agbesọsoke
si OLUWA; ki o si jẹ́ ti alufa ti o nwọ́n ẹ̀jẹ
ẹbọ alafia.
15 Ati ẹran ẹbọ alafia rẹ̀ fun idupẹ́, ki a
jẹ ẹ li ọjọ́ na ti a fi rubọ; ki o máṣe kù
ninu rẹ̀ silẹ titi di owurọ̀.

16 Ṣugbọn bi ẹbo-ọrẹ rẹ̀ ba ṣe ti ẹ̀jẹ́, tabi
ọrẹ-ẹbọ atinuwá, ki a jẹ ẹ li ọjọ́ na ti o ru
ẹbọ rẹ̀: ati ni ijọ́ keji ni ki a jẹ iyokù rẹ̀
pẹlu:
17 Ṣugbọn iyokù ninu ẹran ẹbọ na ni
ijọ́ kẹta ni ki a fi iná sun.
18 Bi a ba si jẹ ninu ẹran ẹbọ alafia rẹ̀
rára ni ijọ́ kẹta, ki yio dà, bẽli a ki yio kà
a si fun ẹniti o ru u: irira ni yio jasi, ọkàn
ti o ba si jẹ ẹ yio rù ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
19 Ẹran ti o ba si kàn ohun aimọ́ kan, a
kò gbọdọ jẹ ẹ: sisun ni ki a fi iná sun u.
Ṣugbọn ẹran na ni, gbogbo ẹniti o mọ́ ni ki
o jẹ ninu rẹ̀.
20 Ṣugbọn ọkàn na ti o ba jẹ ninu ẹran
ẹbọ alafia, ti iṣe ti OLUWA, ti on ti ohun
aimọ́ rẹ̀ lara rẹ̀, ani ọkàn na li a o ke kuro
ninu awọn enia rẹ̀.
21 Pẹlupẹlu ọkàn na ti o ba fọwọkàn
ohun aimọ́ kan, bi aimọ́ enia, tabi ẹranko
alaimọ́, tabi ohun irira elẽri, ti o si jẹ ninu
ẹran ẹbọ alafia, ti iṣe ti OLUWA, ani ọkàn
na li a o ke kuro ninu awọn enia rẹ̀.
22 OLUWA si sọ fun Mose pe,
23 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Ẹnyin
kò gbọdọ jẹ ọrákọra akọmalu, tabi ti agu-
tan, tabi ti ewurẹ.
24 Ati ọrá ẹran ti o tikara rẹ̀ kú, ati ọrá
eyiti ẹranko fàya, on ni ki a ma lò ni ilò
miran: ṣugbọn ẹnyin kò gbọdọ jẹ ẹ.
25 Nitoripe ẹnikẹni ti o ba jẹ ọrá ẹran,
ninu eyiti enia mú rubọ ti a fi iná ṣe si
OLUWA, ani ọkàn ti o ba jẹ ẹ on li a o ke
kuro ninu awọn enia rẹ̀.
26 Pẹlupẹlu ẹnyin kò gbọdọ jẹ ẹ̀jẹ-kẹjẹ,
iba ṣe ti ẹiyẹ tabi ti ẹran, ninu ibugbé nyin
gbogbo.
27 Ọkànkọkàn ti o ba jẹ ẹ̀jẹkẹjẹ, ani
ọkàn na li a o ke kuro ninu awọn enia rẹ̀.
28 OLUWA si sọ fun Mose pe,
29 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Ẹniti o
ba ru ẹbọ alafia rẹ̀ si OLUWA, ki o mú ọrẹ-
ẹbọ rẹ̀ tọ̀ OLUWA wá ninu ẹbọ alafia rẹ̀:
30 Ọwọ́ on tikara rẹ̀ ni ki o fi mú ẹbọ
OLUWA ti a fi iná ṣe wá; ọrá pẹlu igẹ̀ rẹ̀,
on ni ki o múwa, ki a le fi igẹ̀ na li ẹ̀bọ fifì
niwaju OLUWA.
31 Ki alufa na ki o sun ọrá na lori pẹpẹ:
ṣugbọn ki igẹ̀ na ki o jẹ́ ti Aaroni ati ti
awọn ọmọ rẹ̀.
32 Itan ọtún ni ki ẹnyin ki o fi fun
alufa, fun ẹbọ agbesọsoke ninu ẹbọ alafia
nyin.
33 Ninu awọn ọmọ Aaroni ẹniti o rubọ
ẹ̀jẹ ẹbọ alafia, ati ọrá, ni ki o ní itan ọtún
fun ipín tirẹ̀.

Digitized by Google

34 Nitoripe igè fifi ati itan agbesọsoke, ni mo gbà lọwọ awọn ọmọ Israeli ninu ẹbọ alafia wọn, mo si fi wọn fun Aaroni alufa, ati fun awọn ọmọ rẹ̀ nipa ìlana titilai, lati inu awọn ọmọ Israeli.

35 Eyi ni ipín Aaroni, ati ipín awọn ọmọ rẹ̀, ninu ẹbọ OLUWA ti a fi iná ṣe, li ọjọ́ na ti o mú wọn wá lati ṣe alufa OLUWA;

36 Ti OLUWA palaṣẹ lati fi fun wọn lati inu awọn ọmọ Israeli, li ọjọ́ ti o fi oróro yàn wọn. Ilana lailai ni iraniran wọn.

37 Eyi li ofin ẹbọ sisun, ti ẹbọ ohunjijẹ, ati ti ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ti ẹbọ ẹbi, ati ti ìyasimimọ́, ati ti ẹbọ alafia;

38 Ti OLUWA palaṣẹ fun Mose li òke Sinai, li ọjọ́ ti o paṣẹ fun awọn ọmọ Israeli lati ma mú ọrẹ-ẹbọ wọn wá fun OLUWA ni ijù Sinai.

## ORI 8.

OLUWA si sọ fun Mose pe,

2 Mú Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀, ati ẹ̀wu wọnni, ati oróro itasori, ati akọmalu kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati àgbo meji, ati agbọ̀n àkara alaiwu kan;

3 Ki iwọ ki o si pè gbogbo ijọ enia jọ si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ.

4 Mose si ṣe bi OLUWA ti fi aṣẹ fun u; a si pe awọn enia jọ si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ.

5 Mose si wi fun ijọ enia pe, Eyi li ohun ti OLUWA palaṣẹ lati ṣe.

6 Mose si mú Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ wá, o si fi omi wẹ̀ wọn.

7 O si wọ̀ ọ li ẹ̀wu, o si fi amure dì i, o si fi aṣọ igunwa wọ̀ ọ, o si wọ̀ ọ li ẹ̀wu-efodi, o si fi onirũru-ọna ọjá ẹ̀wu-efodi dì i, o si fi gbà a li ọjá.

8 O si dì igbàiya mọ́ ọ; o si fi Urimu ati Tummimu sinu igbàiya na.

9 O si fi fila dé e li ori; ati lara fila na pẹlu, ani niwaju rẹ̀, li o fi awo wurà na si, adé mímọ́ nì; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

10 Mose si mú oróro itasori, o si ta a sara agọ́, ati sara ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀, o si yà wọn simimọ́.

11 O si mú ninu rẹ̀ fi wọ́n ori pẹpẹ nigba meje, o si ta a sara pẹpẹ na, ati si gbogbo ohunèlo rẹ̀, ati agbada ati ẹsẹ̀ rẹ̀, lati yà wọn simimọ́.

12 O si dà ninu oróro itasori si ori Aaroni, o si ta a si i lara, lati yà a simimọ.

13 Mose si mú awọn ọmọ Aaroni wá, o si fi ẹ̀wu wọ̀ wọn, o si fi amure dì wọn, o si fi fila dé wọn li ori; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

14 O si mú akọmalu wá fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ: ati Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ fọwọ́ wọn lé ori akọmalu na fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ.

15 O si pa a; Mose si mú ẹ̀jẹ na, o si fi ika rẹ̀ tọ́ ọ sara iwo pẹpẹ na yiká, o si wẹ̀ pẹpẹ na mọ́, o si dà ẹ̀jẹ na si isalẹ pẹpẹ, o si yà a simimọ́, lati ṣètutu fun u.

16 O si mú gbogbo ọrá ti mbẹ lara ifun, ati àwọn ti o bò ẹ̀dọ, ati iwe mejeji, ati ọrá wọn, Mose si sun u lori pẹpẹ.

17 Ṣugbọn akọmalu na, ati awọ rẹ̀, ati ẹran rẹ̀, ati igbẹ́ rẹ̀, on li o fi iná sun lẹhin ibudó; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

18 O si mú àgbo ẹbọ sisun wá: Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ si fọwọ́ wọn lé ori àgbo na.

19 O si pa a: Mose si fi ẹ̀jẹ na wọ́n ori pẹpẹ yiká.

20 O si kun àgbo na; Mose si sun ori rẹ̀, ati ara rẹ̀, ati orá na.

21 O si ṣìn ifun rẹ̀ ati itan rẹ̀ ninu omi; Mose si sun gbogbo àgbo na lori pẹpẹ: ẹbọ sisun fun õrùn didùn ni: ani ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Moso.

22 O si mú àgbo keji wá, àgbo ìyasimimọ́: Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ si fọwọ́ wọn lé ori àgbo na.

23 O si pa a; Mose si mú ninu ẹ̀jẹ rẹ̀, o si tọ́ ọ si eti ọtún Aaroni, ati si àtampako ọwọ́ ọtún rẹ̀, ati si àtampako ẹsẹ̀ ọtún rẹ̀.

24 O si mú awọn ọmọ Aaroni wá, Mose si tọ́ ninu ẹ̀jẹ na si eti ọtún wọn, ati si àtampako ọwọ́ ọtún wọn, ati si àtampako ẹsẹ̀ ọtún wọn: Mose si fi ẹ̀jẹ na wọ́n ori pẹpẹ yiká.

25 O si mú ọrá na, ati ìru ti o lọrá, ati gbogbo ọrá ti o mbẹ lara ifun, ati àwọn ti o bò ẹ̀dọ, ati iwe mejeji, ati ọrá wọn, ati itan ọtún:

26 Ati lati inu agbọ̀n àkara alaiwu, ti o wà niwaju OLUWA, o mú adidùn àkara alaiwu kan, ati adidùn àkara oloróro kan, ati àkara fẹlẹfẹlẹ kan, o si fi wọn sori ọrá nì, ati si itan ọtún na:

27 O si fi gbogbo rẹ̀ lé Aaroni li ọwọ́, ati lé ọwọ́ awọn ọmọ rẹ̀, o si fì wọn li ẹbọ fifì niwaju OLUWA.

28 Mose si gbà wọn li ọwọ́ wọn, o si sun wọn lori pẹpẹ li ẹbọ sisun: ìyasimimọ́ ni nwọn fun õrùn didùn: ẹbọ ti a fi iná ṣe ni si OLUWA.

29 Mose si mú igẹ̀ ẹran na, o si fì i li ẹbọ fifì niwaju OLUWA: nitori ipín ti Mose ni ninu àgbo ìyasimimọ́; bi OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

30 Mose si mú ninu oróro itasori nì, ati ninu ẹ̀jẹ ti mbẹ lori pẹpẹ, o si fi i wọ́n ara Aaroni, ati ara aṣọ rẹ̀ wọnni, ati ara awọn

Digitized by Google

ọmọ rẹ̀, ati ara aṣọ awọn ọmọ rẹ̀ pelu rẹ̀ ; o
si yà Aaroni simimọ́, ati aṣọ rẹ̀ wọnni, ati
awọn ọmọ rẹ̀, ati aṣọ awọn ọmo rẹ̀ pẹlu rẹ̀.
31 Mose si wi fun Aaroni ati awọn ọmọ
rẹ̀ pe, Ẹ bọ̀ ẹran na li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ :
nibẹ̀ ni ki ẹnyin si jẹ ẹ pẹlu àkara nì ti
mbẹ ninu agbọ̀n ìyasimimọ́, bi mo ti fi aṣẹ
lelẹ wipe, Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ ni ki o
jẹ ẹ.
32 Eyiti o ba si kù ninu ẹran na ati
ninu àkara na ni ki ẹnyin ki o fi iná sun.
33 Ki ẹnyin ki o maṣe jade si ẹnu-ọ̀na
agọ́ ajọ ni ijọ́ meje, titi ọjọ́ ìyasimimọ́ nyin
yio fi pé ; nitori ijọ́ meje ni a o fi yà nyin
simimọ́.
34 Bi o ti ṣe li oni yi, bẹ̃li Oluwa fi aṣẹ
lelẹ lati ṣe, lati ṣètutu fun nyin.
35 Nitorina ni ki ẹnyin ki o joko nibi
ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, li ọsán ati li oru ni ijọ́
meje, ki ẹnyin ki o si ma pa aṣẹ Oluwa
mọ́, ki ẹnyin ki o má ba kú : nitoripe bẹ̃li
a fi aṣẹ fun mi.
36 Bẹ̃li Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ ṣe ohun
gbogbo ti Oluwa ti fi aṣẹ lelẹ lati ọwọ́
Mose wá.

## ORI 9.

O SI ṣe ni ijọ́ kẹjọ, ni Mose pè Aaroni ati
awọn ọmọ rẹ̀, ati awọn àgba Israeli ;
2 O si wi fun Aaroni pe, Mú ọmọ akọ-
malu kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati àgbo kan alaila-
bùku fun ẹbo sisun, ki o fi wọn rubọ niwaju
Oluwa.
3 Ki iwọ ki o si sọ fun awọn ọmọ Israeli
pe, Ẹ mú obukọ kan wá fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ; ati
ọmọ malu kan, ati ọdọ-agutan kan, mejeji
ọlọdún kan, alailabùku, fun ẹbọ sisun ;
4 Ati akọmalu kan ati àgbo kan fun ẹbọ
alafia, lati fi ru ẹbọ niwaju Oluwa ; ati ẹbọ
ohunjijẹ ti a fi oróro pò ; nitoripe li oni li
Oluwa yio farahàn nyin.
5 Nwọn si mú ohun ti Mose filelẹ li aṣẹ
wá siwaju agọ́ ajọ : gbogbo ijọ si sunmọtosi,
nwọn si duro niwaju Oluwa.
6 Mose si wipe, Eyi li ohun ti Oluwa
filelẹ li aṣẹ, ki ẹnyin ki o ṣe : ogo Oluwa
yio si farahàn nyin.
7 Mose si sọ fun Aaroni pe, Sunmọ pẹpẹ,
ki o si ru ẹbọ ẹ̀ṣẹ rẹ, ati ẹbọ sisun rẹ, ki o
si ṣètutu fun ara rẹ, ati fun awọn enia : ki
o si ru ọrẹ-ẹbọ awọn enia, ki o si ṣètutu fun
wọn ; bi Oluwa ti fi aṣẹ lelẹ.
8 Aaroni si sunmọ pẹpẹ, o si pa ọmọ
malu ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ti iṣe ti on tikalarẹ̀.
9 Awọn ọmọ Aaroni si mú ẹ̀jẹ na tọ̀
ọ wá : o si tẹ̀ ika rẹ̀ bọ̀ inu ẹ̀jẹ na, o si
tọ́ ọ sara iwo pẹpẹ, o si dà ẹ̀jẹ na si isalẹ
pẹpẹ :
10 Ṣugbọn ọrá, ati iwe, ati àwọn ti o bò
ẹ̀dọ ti ẹbọ ẹ̀ṣẹ, o sun u lori pẹpẹ ; bi Oluwa
ti fi aṣẹ fun Mose.
11 Ati ẹran ati awọ li o fi iná sun lẹhin
ibudó.
12 O si pa ẹbọ sisun : awọn ọmọ Aaroni
si mú ẹ̀jẹ rẹ̀ tọ̀ ọ wá, o si fi i wọ́n ori pẹpẹ
yiká.
13 Nwọn si mú ẹbọ sisun tọ̀ ọ wá, ti on
ti ipín rẹ̀, ati ori : o si sun wọn lori pẹpẹ.
14 O si ṣin ifun ati itan rẹ̀, o si sun wọn
li ẹbọ sisun lori pẹpẹ.
15 O si mú ọrẹ-ẹbọ awọn enia wá, o si
mú obukọ, ti iṣe ẹbọ ẹ̀ṣẹ fun awọn enia, o
si pa a, o si fi i rubọ ẹṣẹ, bi ti iṣaju.
16 O si mú ẹbọ sisun wá, o si ru u gẹgẹ
bi ìlana na.
17 O si mú ẹbọ ohunjijẹ wá, o si bù
ikunwọ kan ninu rẹ̀, o si sun u lori pẹpẹ,
pẹlu ẹbọ sisun owurọ̀.
18 O si pa akọmalu ati àgbo fun ẹbọ
alafia, ti iṣe ti awọn enia ; awọn ọmọ Aaroni
si mú ẹ̀jẹ na tọ̀ ọ wá, o si fi i wọ́n ori pẹpẹ
yiká.
19 Ati ọrá inu akọmalu na ati ti inu
àgbo na, ìru rẹ̀ ti o lọrá, ati eyiti o bò ifun,
ati iwe, ati àwọn ti o bò ẹ̀dọ :
20 Nwọn si fi ọrá na lé ori igẹ̀ wọnni, o
si sun ọrá na lori pẹpẹ.
21 Ati igẹ̀ na ati itan ọtún ni Aaroni fì
li ẹbọ fifì niwaju Oluwa ; bi Mose ti fi aṣẹ
lelẹ.
22 Aaroni si gbé ọwọ́ rẹ̀ soke si awọn
enia, o si sure fun wọn ; o si sọkalẹ kuro ni
ibi irubọ ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ẹbọ sisun, ati ẹbọ alafia.
23 Mose ati Aaroni si wọ̀ inu agọ ajọ,
nwọn si jade, nwọn si sure fun awọn enia :
ogo Oluwa si farahàn fun gbogbo enia.
24 Iná kan si ti ọdọ Oluwa jade wá, o
si jó ẹbọ sisun ati ọrá ori pẹpẹ na ; nigbati
gbogbo awọn enia ri i, nwọn hó kùhu,
nwọn si dojubolẹ.

## ORI 10.

ATI Nadabu ati Abihu, awọn ọmọ Aaroni,
olukuluku nwọn mú awoturari rẹ̀,
nwọn si fi iná sinu wọn, nwọn si fi turari
sori wọn, nwọn si mú ajeji iná wá siwaju
Oluwa, ti on kò fi aṣẹ fun wọn.
2 Iná si ti ọdọ Oluwa jade, o si run
wọn, nwọn si kú niwaju Oluwa.
3 Nigbana ni Mose wi fun Aaroni pe,
Eyiyi li Oluwa wipe, A o yà mi simimọ́
ninu awọn ti nsunmọ mi, ati niwaju awọn

Digitized by Google

enia gbogbo li a o yìn mi li ogo. Aaroni si dakẹ.

4 Mose si pè Mişaeli ati Elsafani, awọn ọmọ Usieli arakọnrin Aaroni, o si wi fun wọn pe, Ẹ sunmọ ihin, ẹ gbé awọn arakọnrin nyin kuro niwaju ibi mimọ́ jade sẹhin ibudó.

5 Bẽni nwọn sunmọ ibẹ̀, nwọn si gbé ti awọn ti ẹ̀wu wọn jade sẹhin ibudó; bi Mose ti wi.

6 Mose si wi fun Aaroni, ati fun Eleasari ati fun Itamari, awọn ọmọ rẹ̀ pe, Ẹ máse şi ibori nyin, bẽni ki ẹ má si şe fà aşọ nyin ya; ki ẹnyin ki o má ba kú, ati ki ibinu ki o má ba wá sori gbogbo ijọ: şugbọn ki awọn arakọnrin nyin, gbogbo ile Israeli ki o sọkun ijóna ti OLUWA şe yi.

7 Ki ẹnyin ki o má si şe jade kuro lati ibi ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, ki ẹnyin ki o ma ba kú: nitoripe oróro itasori OLUWA mbẹ lara nyin. Nwọn si şe gẹgẹ bi ọ̀rọ Mose.

8 OLUWA si sọ fun Aaroni pe,

9 Máşe mu ọti-waini tabi ọti lile, iwọ, tabi awọn ọmọ rẹ pẹlu rẹ, nigbati ẹnyin ba wọ̀ inu agọ́ ajọ lọ, ki ẹnyin ki o má ba kú: ìlana ni titilai ni iraniran nyin:

10 Ki ẹnyin ki o le ma fi ìyatọ sãrin mimọ́ ati aimọ́, ati sãrin ẽri ati ailẽri;

11 Ati ki ẹnyin ki o le ma kọ́ awọn ọmọ Israeli ni gbogbo ìlana ti OLUWA ti sọ fun wọn lati ọwọ́ Mose wá.

12 Mose si wi fun Aaroni, ati fun Eleasari ati fun Itamari, awọn ọmọ rẹ̀ ti o kù pe, Ẹ mú ẹbọ ohunjijẹ ti o kù ninu ẹbọ OLUWA, ti a fi iná şe, ki ẹ si jẹ ẹ lainí iwukàra lẹba pẹpẹ: nitoripe mimọ́ julọ ni:

13 Ki ẹnyin ki o si jẹ ẹ ni ibi mimọ́, nitoripe ipín tirẹ, ati ipín awọn ọmọ rẹ ni, ninu ẹbọ OLUWA ti a fi iná şe: nitoripe, bẽli a fi aşẹ fun mi.

14 Ati igẹ̀ fifì, ati itan agbesọsoke ni ki ẹnyin ki o jẹ ni ibi mimọ́ kan; iwọ, ati awọn ọmọkọnrin rẹ, ati awọn ọmọbirin rẹ pẹlu rẹ: nitoripe ipín tirẹ ni, ati ipín awọn ọmọ rẹ, ti a fi fun nyin ninu ẹbọ alafia awọn ọmọ Israeli.

15 Itan ágbesọsoke ati igẹ̀ fifì ni ki nwọn ki o ma múwa pọlu ẹbọ ti a fi iná şe ti ọrá, lati fì i fun ẹbọ fifì niwaju OLUWA: yio si ma jẹ́ tirẹ, ati ti awọn ọmọ rẹ pẹlu rẹ, nipa ìlana titilai; bi OLUWA ti fi aşẹ lelẹ.

16 Mose si fi pẹlẹpẹlẹ wá ewurẹ ẹbọ ẹ̀şẹ nì, si kiyesi i, a ti sun u: o si binu si Eleasari ati Itamari, awọn ọmọ Aaroni ti o kù, wipe,

17 Nitori kini ẹnyin kò şe jẹ ẹbọ ẹ̀şẹ na ni ibi mimọ́, nitoripe mimọ́ julọ ni, a si ti fi fun nyin lati rù ẹ̀şẹ ijọ enia, lati şètutu fun wọn niwaju OLUWA?

18 Kiyesi i, a kò mú ẹ̀jẹ rẹ̀ wá sinu ibi mimọ́: ẹnyin iba ti jẹ ẹ nitõtọ ni ibi mimọ́, bi mo ti paşẹ.

19 Aaroni si wi fun Mose pe, Kiyesi i, li oni ni nwọn ru ẹbọ ẹ̀şẹ wọn ati ẹbọ sisun wọn niwaju OLUWA; irú nkan wọnyi li o si şubulù mi: emi iba si ti jẹ ẹbọ ẹ̀şẹ li oni, o ha le dara li oju OLUWA?

20 Nigbati Mose gbọ́ eyĩ inu rẹ̀ si tutù.

## ORI 11.

OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni, o wi fun wọn pe,

2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Wọnyi li ẹranko ti ẹnyin o ma jẹ ninu gbogbo ẹran ti mbẹ lori ilẹ aiye.

3 Ohunkohun ti o ba yà bàta-ẹsẹ̀, ti o si là li ẹsẹ̀, ti o si njẹ apọjẹ, ninu ẹran, on ni ki ẹnyin ki o ma jẹ.

4 Şugbọn wọnyi ni ki ẹ máşe jẹ ninu awọn ti njẹ apọjẹ, tabi awọn ti o si yà bàta-ẹsẹ̀: bi ibakasiẹ, nitoriti o njẹ apọjẹ şugbọn kò yà bàta-ẹsẹ, alaimọ́ li o jasi fun nyin.

5 Ati gara, nitoriti o njẹ apọjẹ, şugbọn kò yà bàta-ẹsẹ̀, alaimọ́ li o jasi fun nyin.

6 Ati ehoro, nitoriti o njẹ apọjẹ, sugbọn kò yà bàta-ẹsẹ̀, alaimọ́ li o jasi fun nyin.

7 Ati ẹlẹdẹ̀, bi o ti yà bàta-ẹsẹ̀, ti o si là ẹsẹ̀, şugbọn on kò jẹ apọjẹ, alaimọ́ li o jasi fun nyin.

8 Ninu ẹran wọn li ẹnyin kò gbọdọ jẹ, okú wọn li ẹnyin kò gbọdọ fọwọkàn; alaimọ́ ni nwọn jasi fun nyin.

9 Wọnyi ni ki ẹnyin ki o ma jẹ ninu gbogbo ohun ti mbẹ ninu omi: ohunkohun ti o ba ní lẹbẹ ati ipẹ́, ninu omi, ninu okun, ati ninu odò, awọn ni ki ẹnyin ki o ma jẹ.

10 Ati gbogbo eyiti kò ní lẹbẹ ati ipẹ́ li okun, ati li odò, ninu gbogbo ohun ti nrá ninu omi, ati ninu ohun alãye kan ti mbẹ ninu omi, irira ni nwọn o jasi fun nyin,

11 Ani irira ni nwọn o ma jẹ́ fun nyin: ẹnyin kò gbọdọ jẹ ninu ẹran wọn, okú wọn ni ẹ o si kàsi irira.

12 Ohunkohun ti kò ba ní lẹbẹ ati ipẹ́, ninu omi, on ni ki ẹnyin kàsi irira fun.

13 Wọnyi li ẹnyin o si ma kàsi irira ninu ẹiyẹ; awọn li a kò gbọdọ jẹ, irira ni nwọn işe: idì, ati aşá-ídì, ati idì-ẹja.

Digitized by Google

14 Ati igún, ati aṣá li onirũru rẹ̀;
15 Ati gbogbo ìwo li onirũru rẹ̀;
16 Ati ogongo, ati owiwi, ati ẹlulu, ati
awodi li onirũru rẹ̀,
17 Ati òyo ati ìgo, ati owiwi;
18 Ati ogbugbu, ati ofú, ati àkala;
19 Ati àkọ, ati ondẹ li onirũru rẹ̀, ati
atọka, ati adán.
20 Gbogbo ohun ti nrakò, ti nfò ti o si
nfi mẹrẹrin rìn ni ki ẹnyin kàsi irira fun
nyin.
21 Ṣugbọn wọnyi ni ki ẹnyin ki o ma jẹ
ninu gbogbo ohun ti nfò, ti nrakò, ti nfi
gbogbo mẹrẹrin rìn, ti o ní tete lori ẹsẹ̀
wọn, lati ma fi ta lori ilẹ;
22 Ani ninu wọnyi ni ki ẹnyin ma jẹ;
eṣú ni irú rẹ̀, ati eṣú onihoho nipa irú rẹ̀,
ati ọbọnbọn nipa irú rẹ̀, ati ẹlẹnga nipa
irú rẹ̀.
23 Ṣugbọn gbogbo ohun iyokù ti nfò ti
nrakò, ti o ní ẹsẹ̀ mẹrin, on ni ki ẹnyin
kàsi irira fun nyin.
24 Nitori wọnyi li ẹnyin o si jẹ́ alaimọ́:
ẹnikẹni ti o ba farakàn okú wọn ki o jẹ́
alaimọ́ titi di aṣalẹ:
25 Ẹnikẹni ti o ba si rù ohun kan ninu
okú wọn ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si jẹ́ alaimọ́
titi di aṣalẹ.
26 Ẹranko gbogbo ti o yà bàta-ẹsẹ̀, ti kò
si là ẹsẹ̀, tabi ti kò si jẹ apọjẹ, ki o jẹ́
alaimọ́ fun nyin: gbogbo ẹniti o ba farakàn
wọn ki o jẹ́ alaimọ́.
27 Ati ohunkohun ti o ba si nrìn lori
ẽkanna rẹ̀, ninu gbogbo onirũru ẹranko, ti
nfi ẹsẹ̀ mẹrẹrin rìn, alaimọ́ ni nwọn fun
nyin: ẹnikẹni ti o ba farakàn okú wọn ki
o jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.
28 Ẹniti o ba si rù okú wọn ki o si fọ̀
aṣọ rẹ̀, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ: alai-
mọ́ ni nwọn fun nyin.
29 Wọnyi ni yio si jasi alaimọ́ fun nyin
ninu ohun ti nrakò lori ilẹ; ase, ati eku,
ati awun nipa irú rẹ̀.
30 Ati ọmọle, ati ahanhan, ati alãmu,
ati agiliti, ati agẹmọ.
31 Wọnyi li alaimọ́ fun nyin ninu gbo-
gbo ohun ti nrakò: ẹnikẹni ti o ba farakàn
okú wọn, ki o jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.
32 Ati lara ohunkohun ti okú wọn ba
ṣubulù, ki o jasi alaimọ́; ibaṣe ohun-èlo
igi, tabi aṣọ, tabi awọ, tabi àpo, ohunèlo ti
o wù ki o ṣe, ninu eyiti a nṣe iṣẹ kan, a kò
gbọdọ má fi bọ̀ inu omi, on o si jasi alaimọ́
titi di aṣalẹ; bẽli a o si sọ ọ di mimọ́.
33 Ati gbogbo ohunèlo amọ̀, ninu eyiti
ọkan ninu okú nwọn ba bọ́ si, ohunkohun
ti o wù ki o wà ninu rẹ̀ yio di alaimọ́, ki
ẹnyin ki o si fọ́ ọ.
34 Ninu onjẹ gbogbo ti a o ba jẹ, ti irú
omi nì ba dà si, yio di alaimọ́: ati ohun
mimu gbogbo ti a o ba mu ninu irú ohun-
èlo na yio di alaimọ́.
35 Ati ohunkohun lara eyiti ninu okú
wọn ba ṣubulù, yio di alaimọ́; iba ṣe àro,
tabí idana, wiwó ni ki a wó wọn lulẹ:
alaimọ́ ni nwọn, nwọn o si jẹ́ alaimọ́ fun
nyin.
36 Ṣugbọn orisun tabi kanga kan, ninu
eyiti omi pupọ̀ gbé wà, yio jẹ́ mimọ́: ṣu-
gbọn eyiti o ba kàn okú wọn yio jẹ́ alaimọ́.
37 Bi ninu okú wọn ba bọ́ sara irugbìn
kan ti iṣe gbigbìn, yio jẹ́ mimọ́.
38 Ṣugbọn bi a ba dà omi sara irugbìn
na, ti ninu okú wọn ba si bọ́ sinu rẹ̀, yio
si jẹ́ alaimọ́ fun nyin.
39 Ati bi ẹran kan, ninu eyiti ẹnyin ba
ma jẹ, ba kú; ẹniti o ba farakàn okú rẹ̀
yio jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.
40 Ẹniti o ba si jẹ ninu okú rẹ̀, ki o si
fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ:
ẹniti o ba si rù okú rẹ̀ ki o si fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki
o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.
41 Ati ohun gbogbo ti nrakò lori ilẹ yio
jasi irira; a ki yio jẹ ẹ.
42 Ohunkohun ti nfi inu wọ́, ati ohun-
kohun ti nfi mẹrẹrin rìn, ati ohunkohun
ti o ba ní ẹsẹ̀ pupọ̀, ani ohun gbogbo ti
nrakò lori ilẹ, awọn li ẹnyin kò gbọdọ jẹ;
nitoripe irira ni nwọn.
43 Ẹnyin kò gbọdọ fi ohun kan ti nrakò,
sọ ara nyin di irira, bẽli ẹnyin kò gbọdọ fi
wọn sọ ara nyin di alaimọ́, ti ẹnyin o fi ti
ipa wọn di elẽri.
44 Nitoripe Emi li OLUWA Ọlọrun nyin:
nitorina ni ki ẹnyin ki o yà ara nyin simi-
mọ́, ki ẹnyin ki o si jẹ mimọ́; nitoripe
mimọ́ li Emi: bẽli ẹnyin kò gbọdọ fi ohun-
kohun ti nrakò sọ ara nyin di elẽri.
45 Nitoripe Emi li OLUWA ti o mú nyin
gòke ti ilẹ Egipti wá, lati ma ṣe Ọlọrun
nyin: nitorina ki ẹnyin ki o jẹ́ mimọ́,
nitoripe mimọ́ li Emi.
46 Eyiyi li ofin ẹranko, ati ti ẹiyẹ, ati
ti ẹda gbogbo alãye ti nrá ninu omi, ati ti
ẹda gbogbo ti nrakò lori ilẹ:
47 Lati fi ìyatọ sãrin aimọ́ ati mimọ́, ati
sãrin ohun alãye ti a ba ma jẹ, ati ohun
alãye ti a ki ba jẹ.

## ORI 12.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Bi

Digitized by Google

obirin kan ba lóyun, ti o si bi ọmọkọnrin, nigbana ni ki o jẹ́ alaimọ́ ni ijọ́ meje; gẹgẹ bi ọjọ́ ìyasọtọ fun ailera rẹ̀ ni ki o jẹ́ alaimọ́.
3 Ni ijọ́ kẹjọ ni ki a si kọ ọmọkọnrin na nilà.
4 Ki obirin na ki o si wà ninu ẹ̀jẹ ìwẹnumọ́ rẹ̀ li ọjọ́ mẹtalelọgbọ̀n; ki o máṣe fọwọkàn ohun mimọ́ kan, bẽni ki o máṣe lọ sinu ibi mimọ́, titi ọjọ́ ìwẹnumọ́ rẹ̀ yio fi pé.
5 Ṣugbọn bi o ba bi ọmọbirin, nigbana ni ki o jẹ́ alaimọ́ li ọsẹ̀ meji, bi ti inu ìyasọtọ rẹ̀: ki o si wà ninu ẹ̀jẹ ìwẹnumọ́ rẹ̀ li ọgọta ọjọ́ o le mẹfa.
6 Nigbati ọjọ́ ìwẹnumọ́ rẹ̀ ba pé, fun ọmọkọnrin, tabi fun ọmọbirin, ki o mú ọdọ-agutan ọlọdún kan wá fun ẹbọ sisun, ati ẹiyẹle, tabi àdaba, fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ tọ̀ alufa wá, si ẹnu-ọ̀na agọ ajọ:
7 Ẹniti yio ru u niwaju Oluwa, ti yio si ṣètutu fun u; on o si di mimọ́ kuro ninu isun ẹ̀jẹ rẹ̀. Eyi li ofin fun ẹniti o bi ọmọkọnrin tabi ọmọbirin.
8 Bi kò ba si le mú ọdọ-agutan wá, njẹ ki o mú àdaba meji, tabi ọmọ ẹiyẹle meji wá; ọkan fun ẹbọ sisun, ati ekeji fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ: alufa yio si ṣètutu fun u, on o si di mimọ́.

## ORI 13.

OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni pe,
2 Nigbati enia kan ba ní iwú, apá, tabi àmi didán kan li awọ ara rẹ̀, ti o si mbẹ li awọ ara rẹ̀ bi àrun ẹ̀tẹ; nigbana ni ki a mú u tọ̀ Aaroni alufa wá, tabi ọkan ninu awọn ọmọ rẹ̀, alufa:
3 Alufa yio si wò àrun ti mbẹ li awọ ara rẹ̀: bi irun ti mbẹ li oju àrun na ba si di funfun, ati ti àrun na li oju rẹ̀ ba jìn jù awọ ara rẹ̀ lọ, àrun ẹ̀tẹ ni: ki alufa ki o si wò o, ki o si pè e li alaimọ́.
4 Bi àmi didán na ba funfun li awọ ara rẹ̀, ati li oju rẹ̀ ti kò si jìn jù awọ lọ, ti irun rẹ̀ kò di funfun, nigbana ni ki alufa ki o sé àlarun na mọ́ ni ijọ́ meje:
5 Ki alufa ki o si wò o ni ijọ́ keje: si kiyesi i, bi àrun na ba duro li oju rẹ̀, ti àrun na kò ba si ràn li ara rẹ̀, nigbana ni ki alufa ki o sé e mọ́ ni ijọ́ meje si i:
6 Ki alufa ki o si tun wò o ni ijọ́ keje: si kiyesi i, bi àrun na ba ṣe bi ẹni wodú, ti àrun na kò si ràn si i li awọ ara, ki alufa ki o pè e ni mimọ́: kìki apá ni: ki o si fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o jẹ́ mimọ́.
7 Ṣugbọn bi apá na ba ràn pupọ̀ si i li awọ ara, lẹhin igbati alufa ti ri i tán fun mimọ́ rẹ̀, alufa yio si tun wò o.
8 Alufa yio wò o, kiyesi i, apá na ràn li awọ ara rẹ̀, nigbana ni ki alufa ki o pè e li alaimọ́: ẹ̀tẹ ni.
9 Nigbati àrun ẹ̀tẹ ba mbẹ li ara enia, nigbana ni ki a mú u tọ̀ alufa wá;
10 Ki alufa ki o si wò o, si kiyesi i, bi iwú na ba funfun li awọ ara rẹ̀, ti o si sọ irun rẹ̀ di funfun, ti õju si mbẹ ninu iwú na,
11 Ẹ̀tẹ lailai ni li awọ ara rẹ̀, ki alufa ki o pè e li alaimọ́: ki o máṣe sé e mọ́; nitoripe alaimọ́ ni.
12 Bi ẹ̀tẹ ba si sọ jade kakiri li awọ ara, ti ẹ̀tẹ na ba si bò gbogbo ara ẹniti o ní àrun na, lati ori rẹ̀ titi dé ẹsẹ̀ rẹ̀, nibikibi ti alufa ba wò;
13 Nigbana ni ki alufa ki o wò o: si kiyesi i, bi ẹ̀tẹ na ba bò gbogbo ara rẹ̀, ki o pè àlarun na ni mimọ́; gbogbo rẹ̀ di funfun: mimọ́ li on.
14 Ṣugbọn ni ijọ́ ti õju na ba hàn ninu rẹ̀, ki o jẹ́ alaimọ́.
15 Ki alufa ki o wò õju na, ki o si pè e li alaimọ́: nitoripe aimọ́ li õju: ẹ̀te ni.
16 Tabi bi õju na ba yipada, ti o si di funfun, ki o si tọ̀ alufa wá,
17 Alufa yio si wò o: si kiyesi i, bi àrun na ba di funfun, nigbana ni ki alufa ki o pè àlarun na ni mimọ́: mimọ́ li on.
18 Ara pẹlu, ninu eyi, ani li awọ ara ti õwo ti sọ, ti o si jiná,
19 Ati ni apá õwo na bi iwú funfun ba mbẹ nibẹ̀, tabi àmi didán, funfun, ti o si ṣe bi ẹni pọ́n ki a si fi i hàn alufa;
20 Alufa yio wò o, si kiyesi i, li oju rẹ̀ bi o ba jìn jù awọ ara lọ, ti irun rẹ̀ si di funfun, ki alufa ki o pè e li alaimọ́: àrun ẹ̀tẹ li o sọ jade ninu õwo na.
21 Ṣugbọn bi alufa na ba wò o, si kiyesi i, ti irun funfun kò si sí ninu rẹ̀, bi kò ba si jìn jù awọ ara lọ, ti o si dabi ẹni wodú, nigbana ni ki alufa ki o sé e mọ́ ni ijọ́ meje:
22 Bi o ba si ràn siwaju li awọ ara rẹ̀, nigbana ni ki alufa ki o pé e ni alaimọ́: àrun ni.
23 Ṣugbọn bi àmi didán na ba duro ni ipò rẹ̀, ti kò si ràn, õwo tita ni; ki alufa ki o si pè e ni mimọ́.
24 Tabi bi ara kan ba mbẹ, ninu awọ ara eyiti ijóni bi iná ba wà, ti õju jijóna na ba ní àmi funfun didán, ti o ṣe bi ẹni pọn rusurusu tabi funfun;
25 Nigbana ni ki alufa ki o wò o: si

D

Digitized by Google

kiyesi i, bi irun ninu àmi didán na ba di
funfun, ti o ba si jìn jù awọ ara lọ li oju;
ẹ̀tẹ li o ti inu ijóni nì sọ jade; nitorina ni
ki alufa ki o pè e ni alaimọ́: àrun ẹ̀tẹ ni.
26 Ṣugbọn bi alufa ba wò o, si kiyesi i,
ti kò sí irun funfun li apá didán na, ti kó
si jìn ju awọ ara iyokù lọ, ṣugbọn ti o ṣe bi
ẹni wodú; nigbana ni ki alufa ki o sé e mọ́
ni ijọ́ meje:
27 Ki alufa ki o si wò o ni ijọ́ keje: bi
o ba si ràn siwaju li awọ ara rẹ̀, nigbana ni
ki alufa ki o pè e li alaimọ́; àrun ẹ̀tẹ ni.
28 Bi àmi didán na ba si duro ni ipò rẹ̀,
ti kò si ràn si i li awọ ara, ṣugbọn ti o dabi
ẹni wodú: iwú ijóni ni, ki alufa ki o si pè
e ni mimọ́: nitoripe ijóni tita ni.
29 Bi ọkọnrin tabi obirin kan ba ní àrun
li ori rẹ̀ tabi li àgbọn,
30 Nigbana ni ki alufa ki o wò àrun na:
si kiyesi i, bi o ba jìn jù awọ ara lọ li oju,
bi irun tinrin pupa ba mbẹ ninu rẹ̀, nigbana
ni ki alufa ki o pè e li aimọ́: ipẹ́ gbigbẹ
ni, ani ẹ̀tẹ li ori tabi li àgbọn ni.
31 Bi alufa ba si wò àrun pipa na, si ki-
yesi i, ti kò ba jìn jù awọ ara lọ li oju, ti
kò si sí irun dudu ninu rẹ̀, nigbana ni ki
alufa ki o sé alarun pipa na mọ́ ni ijọ́
meje:
32 Ni ijọ́ keje ki alufa ki o si wò àrun
na: si kiyesi i, bi pipa na kò ba ràn, ti kò
si sí irun pupa ninu rẹ̀, ti pipa na kò si jìn
jù awọ ara lọ li oju,
33 Ki o fári, ṣugbọn ki o máṣe fá ibi
pipa na; ki alufa ki o si sé ẹni pipa nì mọ́
ni ijọ́ meje si i:
34 Ni ijọ́ keje ki alufa ki o si wò pipa
na; si kiyesi i bi pipa na kò ba ràn si awọ
ara, ti kò ba jìn jù awọ ara lọ li oju; ni-
gbana ni ki alufa ki o pè e ni mimọ́: ki o
si fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si jẹ́ mimọ́.
35 Ṣugbọn bi pipa na ba ràn siwaju li
awọ ara rẹ̀ lẹhin ìpenimimọ́ rẹ̀;
36 Nigbana ni ki alufa ki o wò o: si
kiyesi i, bi pipa na ba ràn siwaju li awọ
ara, ki alufa ki o máṣe wá irun pupa mọ́;
alaimọ́ ni.
37 Ṣugbọn li oju rẹ̀ bi pipa na ba duro,
ti irun dudu si hù ninu rẹ̀; pipa na jiná,
mimọ́ li on: ki alufa ki o pè e ni mimọ́.
38 Bi ọkọnrin kan tabi obirin kan ba ní
àmi didán li awọ ara wọn, ani àmi funfun
didán;
39 Nigbana ni ki alufa ki o wò o: si ki-
yesi i, bi àmi didán li awọ ara wọn ba ṣe
bi ẹni ṣe funfun ṣe dudu; ifinra li o sọ jade
li ara; mimọ́ li on.
40 Ati ọkọnrin ti irun rẹ̀ ba re kuro li
ori rẹ̀, apari ni; ṣugbọn mimọ́ li on.
41 Ẹniti irun rẹ̀ ba re silẹ ni ìha iwaju
rẹ̀, o pari ni iwaju; ṣugbọn mimọ́ li on.
42 Bi õju funfun-pupa rusurusu ba mbẹ
li ori pipa na, tabi iwaju ori pipa na; ẹ̀tẹ
li o sọ jade ninu pipa ori na, tabi ni pipa
iwaju na.
43 Nigbana ni ki alufa ki o wò o: si ki-
yesi i, bi iwú õju na ba funfun pupa rusu-
rusu ni pipa ori rẹ̀, tabi pipa iwaju rẹ̀, bi
ẹ̀tẹ ti ihàn li awọ ara;
44 Ẹlẹtẹ ni, alaimọ́ ni: ki alufa ki o pè
e li aimọ́ patapata; àrun rẹ̀ mbẹ li ori rẹ̀.
45 Ati adẹ́tẹ na, li ara ẹniti àrun na gbé
wà, ki o fà aṣọ rẹ̀ ya, ki o si fi ori rẹ̀ silẹ ni
ìhoho, ki o si fi ìbo bò ète rẹ̀ òke, ki o si
ma kepe, Alaimọ́, alaimọ́.
46 Ni gbogbo ọjọ́ ti àrun na mbẹ li ara
rẹ̀ ni ki o jẹ́ elẽri; alaimọ́ ni: on nikan ni
ki o ma gbé; lẹhin ibudó ni ibujoko rẹ̀ yio
gbé wà.
47 Ati aṣọ ti àrun ẹ̀tẹ mbẹ ninu rẹ̀, iba
ṣe aṣọ kubusu, tabi aṣọ ọ̀gbọ;
48 Iba ṣe ni ita, tabi ni iwun ti ọ̀gbọ,
tabi ti kubusu; iba ṣe li awọ, tabi ohun
kan ti a fi awọ ṣe;
49 Bi àrun na ba ṣe bi ọbẹ̀do tabi bi pu-
pa lara aṣọ na, tabi lara awọ na, iba ṣe ni
ita, tabi ni iwun, tabi ninu ohunèlo awọ
kan; àrun ẹ̀tẹ ni, ki a si fi i hàn alufa:
50 Ki alufa ki o si wò àrun na, ki o si sé
ohun ti o ní àrun na mọ́ ni ijọ́ meje:
51 Ki o si wò àrun na ni ijọ́ keje: bi
àrun na ba ràn sara aṣọ na, iba ṣe ni ita,
tabi ni iwun, tabi ninu awọ, tabi ninu
ohun ti a fi awọ ṣe; àrun na ẹ̀tẹ kikẹ̀ ni;
alaimọ́ ni.
52 Nitorina ki o fi aṣọ na jóna, iba ṣe
ita, tabi iwun, ni kubusu tabi li ọ̀gbọ, tabi
ninu ohunèlo awọ kan, ninu eyiti àrun na
gbé wà: nitoripe ẹ̀tẹ kikẹ̀ ni; ki a fi jóna.
53 Bi alufa ba si wò, si kiyesi i, ti àrun
na kò ba tàn sara aṣọ na, iba ṣe ni ita, tabi
ni iwun, tabi ninu ohunèlo kan ti a fi
awọ ṣe;
54 Nigbana ni ki alufa ki o paṣẹ ki
nwọn ki o fọ̀ ohun na ninu eyiti àrun na
gbé wà, ki o si sé e mọ́ ni ijọ́ meje si i.
55 Ki alufa ki o si wò àrun na, lẹhin
igbati a fọ̀ ọ tán: si kiyesi i, bi àrun na
kò ba pa awọ rẹ̀ dà, ti àrun na kò si ràn si
i, alaimọ́ ni; ninu iná ni ki iwọ ki o sun
u; o kẹ̀ ninu, iba gbo ninu tabi lode.
56 Bi alufa ba si wò, si kiyesi i, ti àrun
na ba ṣe bi ẹni wodú lẹhin igbati o ba fọ̀ ọ

Digitized by Google

tán ; nigbana ni ki o fà a ya kuro ninu aṣọ
na, tabi ninu awọ na, tabi ninu ita, tabi
ninu iwun :
57 Bi o ba si hàn sibẹ̀ ninu aṣọ na, iba
ṣe ni ita, tabi ni iwun, tabi ninu ohunèlo
kan ti a fi awọ ṣe, àrun riràn ni : ki iwọ ki
o fi iná sun ohun ti àrun na wà ninu rẹ̀.
58 Ati aṣọ na, iba ṣe ni ita, tabi ni
iwun, tabi ninu ohunkohun ti a fi awọ ṣe,
ti iwọ ba fọ̀, bi àrun na ba wọ́n kuro ninu
wọn nigbana ni ki a tun fọ̀ ọ lẹkeji, on o si
jẹ́ mimọ́.
59 Eyi li ofin àrun ẹ̀tẹ, ninu aṣọ, kubusu
tabi ti ọ̀gbọ, iba ṣe ni ita, tabi ni iwun,
tabi ohunkohun èlo awọ kan, lati pè e ni
mimọ́, tabi lati pè e li aimọ́.

## ORI 14.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Eyi ni yio ma ṣe ofin adẹ́tẹ li ọjọ́
ìwẹnumọ́ rẹ̀ : ki a mú u tọ̀ alufa wá :
3 Ki alufa ki o si jade sẹhin ibudó ; ki
alufa ki o si wò o, si kiyesi i, bi àrun ẹ̀tẹ
na ba jiná li ara adẹ́tẹ na :
4 Nigbana ni ki alufa ki o paṣẹ pe, ki a
mú ãye ẹiyẹ meji mimọ́ wá, fun ẹniti a o
wẹ̀numọ́, pẹlu igi opepe, ati ododó, ati
ewe-hissopu :
5 Ki alufa ki o paṣẹ pe ki a pa ọkan
ninu ẹiyẹ nì ninu ohunèlo amọ li oju omi
ti nṣàn :
6 Niti ẹiyẹ alãye, ki o mú u, ati igi
opepe, ati ododó, ati ewe-hissopu, ki o si fi
wọn ati ẹiyẹ alãye nì bọ̀ inu ẹ̀jẹ ẹiyẹ ti a pa
li oju omi ti nṣàn :
7 Ki o si wọ́n ẹniti a o wẹ̀numọ́ kuro
ninu ẹ̀tẹ nigba meje, ki o si pè e ni mimọ́,
ki o si jọwọ ẹiyẹ alãye nì lọwọ lọ si gban-
gba oko.
8 Ki ẹniti a o wẹ̀numọ́ nì ki o si fọ̀ aṣọ
rẹ̀, ki o si fá gbogbo irun ori rẹ̀ kuro, ki o
si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o le mọ́ : lẹhin
eyinì ni ki o wọ̀ ibudó, ṣugbọn ki o gbé
ẹhin ode agọ́ rẹ̀ ni ijọ́ meje.
9 Yio si ṣe ni ijọ́ keje, ni ki o fá gbogbo
irun ori rẹ̀ kuro li ori rẹ̀, ati irungbọn rẹ̀,
ati ipenpeju rẹ̀, ani gbogbo irun rẹ̀ ni ki o
fá kuro : ki o si fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀
pẹlu ninu omi, on o si di mimọ́.
10 Ni ijọ́ kẹjọ ki o mú ọdọ-agutan meji
akọ alailabùku wá, ati ọdọ-agutan kan abo
ọlọdún kan alailabùku, ati idamẹwa mẹta
òṣuwọn deali iyẹfun didara fun ẹbọ ohun-
jijẹ, ti a fi oróro pò, ati òṣuwọn logu oróro
kan.
11 Ki alufa ti o sọ ọ di mimọ́ ki o mú
ọkọnrin na ti a o sọ di mimọ́ ati nkan
wọnni wá, siwaju OLUWA, si ẹnu-ọ̀na agọ́
ajọ :
12 Ki alufa ki o mú akọ ọdọ-agutan kan,
ki o si fi i ru ẹbọ ẹbi, ati òṣuwọn logu
oróro, ki o si fì wọn li ẹbọ fifì niwaju
OLUWA :
13 Ki o si pa akọ ọdọ-agutan na ni ibiti
on o gbé pa ẹbọ ẹ̀ṣẹ ati ẹbọ sisun, ni ibi
mimọ́ nì : nitoripe bi ẹbọ ẹ̀ṣẹ ti jẹ́ ti alufa,
bẹ̃ si ni ẹbọ irekọja : mimọ́ julọ ni :
14 Ki alufa ki o si mú ninu ẹ̀jẹ ẹbọ ẹbi
na, ki alufa ki o si fi i si eti ọtún ẹniti a o
wẹ̀numọ́, ati si àtampako ọwọ́ ọtún rẹ̀, ati
si àtampako ẹsẹ̀ ọtún rẹ̀ :
15 Ki alufa ki o si mú ninu oróro òṣu-
wọn logu na, ki o si dà a si atẹlẹwọ òsi ara
rẹ̀ :
16 Ki alufa ki o si tẹ̀ ika rẹ̀ ọtún bọ̀ inu
oróro na ti mbẹ li ọwọ́ òsi rẹ̀, ki o si fi ika rẹ̀
ta ninu oróro na nigba meje niwaju OLUWA :
17 Ati ninu oróro iyokù ti mbẹ li ọwọ́
rẹ̀ ni ki alufa ki o fi si etí ọtún ẹniti a o
wẹ̀numọ́, ati si àtampako ọwọ́ ọtún rẹ̀, ati
si àtampako ẹsẹ̀ ọtún rẹ̀, lori ẹ̀jẹ ẹbọ ẹbi :
18 Ati oróro iyokù ti mbẹ li ọwọ́ alufa
ni ki o dà si ori ẹniti a o wẹ̀numọ́ : ki
alufa ki o si ṣètutu fun u niwaju OLUWA.
19 Ki alufa ki o si ru ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ki o si
ṣètutu fun ẹniti a o wẹ̀numọ́ kuro ninu
aimọ́ rẹ̀ ; lẹhin eyinì ni ki o pa ẹran ẹbọ
sisun.
20 Ki alufa ki o si ru ẹbọ sisun, ati ẹbọ
ohunjijẹ lori pẹpẹ : ki alufa ki o ṣètutu fun
u, on o si di mimọ́.
21 Bi o ba si ṣe talaka, ti kò le mú tobẹ̃
wá, njẹ ki o mú akọ ọdọ-agutan kan wá
fun ẹbọ ẹbi lati fì, lati ṣètutu fun u, ati
ọkan ninu idamẹwa òṣuwọn deali iyẹfun
daradara ti a fi oróro pò fun ẹbọ ohunjijẹ,
ati òṣuwọn logu oróro kan ;
22 Ati àdaba meji, tabi ọmọ ẹiyẹle meji,
irú eyiti ọwọ́ rẹ̀ ba to ; ki ọkan ki o si ṣe
ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ki ekeji ki o si ṣe ẹbọ sisun.
23 Ki o si mú wọn tọ̀ alufa wá ni ijọ́
kẹjọ fun ìwẹnumọ́ rẹ̀, si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ,
niwaju OLUWA.
24 Ki alufa ki o si mú ọdọ-agutan ẹbọ
ẹbi, ati òṣuwọn logu oróro, ki alufa ki o si
fì wọn li ẹbọ fifì niwaju OLUWA.
25 Ki o si pa ọdọ-agutan ẹbọ ẹbi, ki
alufa ki o si mú ninu ẹ̀jẹ ẹbọ ẹbi na, ki o
si fi i si etí ọtún ẹniti a o wẹ̀numọ́, ati si
àtampako ọwọ́ ọtún rẹ̀, ati si àtampako
ẹsẹ̀ ọtún rẹ̀.

Digitized by Google

26 Ki alufa ki o si dà ninu oróro na si atẹlẹwọ òsi ara rẹ̀:

27 Ki alufa ki o si fi ika rẹ̀ ọtún ta ninu oróro na ti mbẹ li ọwọ́ òsi rẹ̀ nigba meje niwaju OLUWA:

28 Ki alufa ki o si fi ninu oróro na ti mbẹ li ọwọ́ rẹ̀ si eti ọtún ẹniti a o wẹ̀numọ́, ati si àtampako ọwọ́ ọtún rẹ̀, ati si àtampako ẹsẹ̀ ọtún rẹ̀, si ibi ẹ̀jẹ ẹbọ ẹbi:

29 Ati oróro iyokù ti mbẹ li ọwọ́ alufa ni ki o fi si ori ẹniti a o wẹ̀numọ́, lati ṣètutu fun u niwaju OLUWA.

30 Ki o si fi ọkan ninu àdaba nì rubọ, tabi ọkan ninu ọmọ ẹiyẹle nì, iru eyiti ọwọ́ rẹ̀ ba to:

31 Ani irú eyiti apa rẹ̀ ka, ọkan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ekeji fun ẹbọ sisun, pẹlu ẹbọ ohunjijẹ: ki alufa ki o si ṣètutu fun ẹniti a o wẹ̀numọ́ niwaju OLUWA.

32 Eyi li ofin rẹ̀ li ara ẹniti àrun ẹ̀tẹ wà, apa ẹniti kò le ka ohun ìwẹnumọ́ rẹ̀.

33 OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni pe,

34 Nigbati ẹnyin ba dé ilẹ Kenaani, ti mo fi fun nyin ni ilẹ-iní, ti mo ba si fi àrun ẹ̀tẹ sinu ile kan ninu ilẹ-iní nyin;

35 Ti onile na si wá ti o si wi fun alufa pe, O jọ li oju mi bi ẹnipe àrun mbẹ ninu ile na:

36 Nigbana ni ki alufa ki o fun wọn li aṣẹ, ki nwọn ki o kó ohun ile na jade, ki alufa ki o to wọ̀ inu rẹ̀ lọ lati wò àrun na, ki ohun gbogbo ti mbẹ ninu ile na ki o máṣe jẹ́ alaimọ́: lẹhin eyinì ni ki alufa ki o wọ̀ ọ lati wò ile na:

37 Ki o si wò àrun na, si kiyesi i, bi àrun na ba mbẹ lara ogiri ile na pẹlu ìla gbòrogbòro, bi ẹni ṣe bi ọbẹ̀dò tabi pupa rusurusu, ti o jìn li oju jù ogiri lọ;

38 Nigbana ni ki alufa ki o jade ninu ile na si ẹnu-ọ̀na ile na, ki o si há ilẹkun ile na ni ijọ́ meje:

39 Ki alufa ki o tun wá ni ijọ́ keje, ki o si wò o: si kiyesi i, bi àrun na ba ràn lara ogiri ile na;

40 Nigbana ni ki alufa ki o paṣẹ ki nwọn ki o yọ okuta na kuro lara eyiti àrun na gbé wà, ki nwọn ki o si kó wọn lọ si ibi aimọ́ kan lẹhin ilu na.

41 Ki o si mu ki nwọn ki o ha inu ile na yiká kiri, ki nwọn ki o kó erupẹ ti a ha nì kuro lọ si ẹhin ilu na si ibi aimọ́ kan:

42 Ki nwọn ki o si mú okuta miran, ki nwọn ki o si fi i di ipò okuta wọnni, ki nwọn ki o si mú ọrọ miran ki nwọn ki o si fi rẹ́ ile na.

43 Bi àrun na ba si tun pada wá, ti o si tun sọ jade ninu ile na, lẹhin igbati nwọn ba yọ okuta wọnni kuro, ati lẹhin igbati nwọn ba ha ile na, ati lẹhin igbati nwọn ba rẹ́ ẹ;

44 Nigbana ni ki alufa ki o wá, ki o wò o, si kiyesi i, bi àrun ba ràn si i ninu ile na, ẹ̀tẹ kikẹ̀ ni mbẹ ninu ile na: aimọ́ ni.

45 Ki o si wó ile na, okuta rẹ̀, ati ìti igi rẹ̀, ati gbogbo erupẹ ile na; ki o si kó wọn jade kuro ninu ilu na lọ si ibi aimọ́ kan.

46 Ẹniti o ba si wọ̀ ile na ni gbogbo ìgba na ti a sé e mọ́, ki o jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

47 Ẹniti o ba dubulẹ ninu ile na ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀: ẹniti o jẹun ninu ile na ki o si fọ̀ aṣọ rẹ̀.

48 Ati bi alufa ba wọ̀ ile, ti o si wò o, si kiyesi i, ti àrun inu ile na kò ba ràn si i, lẹhin igbati a rẹ́ ile na tán; nigbana ni ki alufa ki o pè ile na ni mimọ́, nitoripe àrun na ti jiná.

49 Ki o si mú ẹiyẹ meji, ati igi opepe, ati ododó, ati ewe-hissopu wá, lati wẹ̀ ile na mọ́:

50 Ki o si pa ọkan ninu ẹiyẹ na, ninu ohunèlo amọ loju omi ti nṣàn:

51 Ki o si mú igi opepe, ati ewe-hissopu, ati ododó, ati ẹiyẹ alãye nì, ki o si tẹ̀ wọn bọ̀ inu ẹ̀jẹ ẹiyẹ ti a pa nì, ati ninu omi ṣiṣàn nì, ki o si fi wọ́n ile na nigba meje:

52 Ki o si fi ẹ̀jẹ ẹiyẹ na wẹ̀ ile na mọ́, ati pẹlu omi ṣiṣàn nì, ati pẹlu ẹiyẹ alãye nì, ati pẹlu igi opepe nì, ati pẹlu ewe-hissopu nì, ati pẹlu ododó:

53 Ṣugbọn ki o jọwọ ẹiyẹ alãye nì lọwọ lọ kuro ninu ilu lọ sinu gbangba oko, ki o si ṣètutu si ile na: yio si di mimọ́.

54 Eyi li ofin fun gbogbo onirũru àrun ẹ̀tẹ, ati ipẹ́;

55 Ati fun ẹ̀tẹ aṣọ, ati ti ile;

56 Ati fun wiwu, ati fun apá, ati fun àmi didán:

57 Lati kọni nigbati o ṣe alaimọ́, ati nigbati o ṣe mimọ́: eyi li ofin ẹ̀tẹ.

## ORI 15.

OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni pe,

2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi fun wọn pe, Nigbati ẹnikan ba ní àrun isun lara rẹ̀, nitori isun rẹ̀ alaimọ́ li on.

3 Eyi ni yio si jẹ́ aimọ́ rẹ̀ ninu isun rẹ̀: ara rẹ̀ iba ma sun isun rẹ̀, tabi bi ara rẹ̀ si dá kuro ninu isun rẹ̀, aimọ́ rẹ̀ ni iṣe.

Digitized by Google

4 Gbogbo ori akete ti ẹniti o ní isun na ba dubulẹ lé, aimọ́ ni: ati gbogbo ohun ti o joko lé yio jẹ́ alaimọ́.

5 Ẹnikẹni ti o ba farakàn akete rẹ̀ ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

6 Ẹniti o si joko lé ohunkohun ti ẹniti o ní isun ti joko lé, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

7 Ẹniti o si farakàn ara ẹniti o ní isun, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

8 Bi ẹniti o ní isun ba tutọ sara ẹniti o mọ́; nigbana ni ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

9 Ati asákasá ti o wù ki ẹniti o ní isun ki o gùn ki o jẹ́ alaimọ́.

10 Ẹnikẹni ti o ba farakàn ohun kan ti o wà nisalẹ rẹ̀, ki o jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ: ati ẹniti o rù ohun kan ninu nkan wọnni, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

11 Ati ẹnikẹni ti ẹniti o ní isun ba farakàn, ti kò ti wẹ̀ ọwọ́ rẹ̀ ninu omi, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

12 Ati ohunèlo amọ̀, ti ẹniti o ní isun ba fọwọkàn, fifọ́ ni ki a fọ́ ọ: ati gbogbo ohunèlo igi ni ki a ṣìn ninu omi.

13 Nigbati ẹniti o ní isun ba si di mimọ́ kuro ninu isun rẹ̀, nigbana ni ki o kà ijọ́ meje fun ara rẹ̀, fun isọdimimọ́ rẹ̀, ki o si fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi ti nṣàn, yio si jẹ́ mimọ́.

14 Ati ni ijọ́ kẹjọ, ki o mú àdaba meji, tabi ọmọ ẹiyẹle meji fun ara rẹ̀, ki o si wá siwaju Oluwa si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, ki o si fi wọn fun alufa:

15 Ki alufa ki o si fi wọn rubọ, ọkan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ekeji fun ẹbọ sisun; ki alufa ki o si ṣètutu fun u niwaju Oluwa nitori isun rẹ̀.

16 Ati bi ohun irú ìdapọ ọkọnrin ba ti ara rẹ̀ jade, nigbana ni ki o wẹ̀ gbogbo ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

17 Ati gbogbo aṣọ, ati gbogbo awọ, lara eyiti ohun irú ìdapọ ba wà, on ni ki a fi omi fọ̀, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

18 Ati obirin na, ẹniti ọkọnrin ba bá dàpọ ti on ti ohun irú ìdapọ, ki awọn mẹjeji ki o wẹ̀ ninu omi, ki nwọn ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

19 Bi obirin kan ba si ní isun, ti isun rẹ̀ li ara rẹ̀ ba jasi ẹ̀jẹ, ki a yà a sapakan ni ijọ́ meje: ẹnikẹni ti o ba si farakàn a, ki o jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

20 Ati ohun gbogbo ti o dubulẹ lé ninu ile ìyasapakan rẹ̀ yio jẹ́ aimọ́: ohunkohun pẹlu ti o joko lé yio jẹ́ aimọ́.

21 Ati ẹnikẹni ti o ba farakàn akete rẹ̀, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

22 Ati ẹnikẹni ti o ba farakàn ohun kan ti o joko lé, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

23 Bi o ba si ṣepe lara akete rẹ̀ ni, tabi lara ohun ti o joko lé, nigbati o ba farakàn a, ki on ki o jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

24 Bi ọkọnrin kan ba si bá a dàpọ rára, ti ohun obirin rẹ̀ ba mbẹ lara ọkọnrin na, ki on ki o jẹ́ alaimọ́ ni ijọ́ meje; ati gbogbo akete ti on dubulẹ lé ki o jẹ́ aimọ́.

25 Ati bi obirin kan ba ní isun ẹ̀jẹ li ọjọ́ pupọ̀ le ìgba ìyasapakan rẹ̀; tabi bi o ba si sun rekọja ìgba ìyasapakan rẹ̀; gbogbo ọjọ́ isun aimọ́ rẹ̀ yio si ri bi ọjọ́ ìyasapakan rẹ̀: o jẹ́ alaimọ́.

26 Gbogbo akete ti o dubulẹ lé ni gbogbo ọjọ́ isun rẹ̀ ki o si jẹ́ fun u bi akete ìyasapakan rẹ̀: ati ohunkohun ti o joko lé ki o jẹ́ aimọ́, bi aimọ́ ìyasapakan rẹ̀.

27 Ati ẹnikẹni ti o ba farakàn nkan wọnni ki o jẹ́ alaimọ́, ki o si fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

28 Ṣugbọn bi obirin na ba di mimọ́ kuro ninu isun rẹ̀, nigbana ni ki o kà ijọ́ meje fun ara rẹ̀, lẹhin eyinì ni ki o si jẹ́ mimọ́.

29 Ati ni ijọ́ kẹjọ ki o mú àdaba meji, tabi ọmọ ẹiyẹle meji fun ara rẹ̀, ki o si mú wọn tọ̀ alufa wá, si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ.

30 Ki alufa ki o si ru ọkan li ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ekeji li ẹbọ sisun; ki alufa ki o si ṣètutu fun u niwaju Oluwa nitori isun aimọ́ rẹ̀.

31 Bayi ni ki ẹnyin ki o yà awọn ọmọ Israeli kuro ninu aimọ́ wọn; ki nwọn ki o má ba kú ninu aimọ́ wọn, nigbati nwọn ba sọ ibugbé mi ti mbẹ lãrin wọn di aimọ́.

32 Eyi li ofin ẹniti o ní isun, ati ti ẹniti ohun irú rẹ̀ jade lara rẹ̀, ti o si ti ipa rẹ̀ di alaimọ́;

33 Ati ti ẹniti o ri ohun obirin rẹ̀, ati ti ẹniti o ní isun, ati ti ọkọnrin, ati ti obirin, ati ti ẹniti o ba bá ẹniti iṣe alaimọ́ dàpọ.

## ORI 16.

OLUWA si sọ fun Mose lẹhin ikú awọn ọmọ Aaroni meji, nigbati nwọn rubọ niwaju Oluwa, ti nwọn si kú;

Digitized by Google

2 Oluwa si sọ fun Mose pe, Sọ fun
Aaroni arakọnrin rẹ, ki o máṣe wá nigba-
gbogbo sinu ibi mimọ́, ninu aṣọ-ikele niwa-
ju itẹ́-ãnu, ti o wà lori apoti nì; ki o má
ba kú: nitoripe emi o farahàn ninu awọ-
sanma lori itẹ́-ãnu.
3 Bayi ni ki Aaroni ki o ma wá sinu ibi
mimọ́: pẹlu ẹgbọrọ akọmalu fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ,
ati àgbo fun ẹbọ sisun.
4 Ki o si mú ẹ̀wu ọ̀gbọ mimọ́ wọ̀, ki o
si bọ̀ ṣòkoto ọ̀gbọ nì si ara rẹ̀, ki a si fi
amure ọ̀gbọ kan dì i, fila ọ̀gbọ ni ki a fi ṣe
e li ọṣọ́: aṣọ mimọ́ ni wọnyi; nitorina ni o
ṣe wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si mù wọn wọ̀.
5 Ki o si gbà ọmọ ewurẹ meji akọ, fun
ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati àgbo kan fun ẹbọ sisun, lọwọ
ijọ awọn ọmọ Israeli.
6 Ki Aaroni ki o si fi akọmalu ru ẹbọ
ẹ̀ṣẹ, ti iṣe ti on tikara rẹ, ki o si ṣètutu fun
ara rẹ̀, ati fun ile rẹ̀.
7 Ki o si mú ewurẹ meji nì, ki o si mú
wọn wá siwaju Oluwa si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ.
8 Ki Aaroni ki o si di ìbo ewurẹ meji
na; ìbo kan fun Oluwa, ati ìbo keji fun
Asaseli (ewurẹ idasilẹlọ).
9 Ki Aaroni ki o si mú ewurẹ ti ìbo
Oluwa mú wá, ki o si fi ru ẹbọ ẹ̀ṣẹ.
10 Ṣugbọn ewurẹ ti ìbo mú fun Asaseli
on ni ki o múwa lãye siwaju Oluwa, lati
fi i ṣètutu, ati ki o si jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ si ijù
fun Asaseli.
11 Ki Aaroni ki o si mú akọmalu ẹbọ
ẹ̀ṣẹ wá, ti iṣe ti on tikararẹ̀, ki o si ṣètutu
fun ara rẹ̀, ati fun ile rẹ̀, ki o si pa akọma-
lu ẹbọ ẹ̀ṣẹ ti iṣe fun ara rẹ̀:
12 Ki o si mú awo-turari ti o kún fun
ẹyin iná lati ori pẹpẹ wá lati iwaju Oluwa,
ki ọwọ́ rẹ̀ ki o si kún fun turari didùn ti a
gún kunná, ki o si mú u wá sinu aṣọ-ikele:
13 Ki o si fi turari na sinu iná niwaju
Oluwa, ki ẽfin turari ki o le bò itẹ́-ãnu ti
mbẹ lori ẹri, ki on ki o má ba kú.
14 Ki o si mú ninu ẹ̀jẹ akọmalu na, ki o
si fi ika rẹ̀ wọn ọ sori itẹ́-ãnu ni ìha ìla-
õrùn; ati niwaju itẹ́-ãnu ni ki o fi ika rẹ̀
wọ́n ninu ẹ̀jẹ na nigba meje.
15 Nigbana ni ki o pa ewurẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ,
eyiti iṣe ti awọn enia, ki o si mú ẹ̀jẹ rẹ̀ wá
sinu aṣọ-ikele, ki o si fi ẹ̀jẹ na ṣe bi o ti fi
ẹ̀jẹ akọmalu ṣe, ki o si fi wọ́n ori itẹ́-ãnu,
ati niwaju itẹ́-ãnu:
16 Ki o si ṣètutu si ibi mimọ́ nì, nitori
aimọ́ awọn ọmọ Israeli, ati nitori irekọja
wọn, ani gbogbo ẹ̀ṣẹ wọn: bẽni ki o si ṣe
si agọ́ ajọ, ti mbẹ lọdọ wọn ninu aimọ́ wọn.
17 Ki o má si sí ẹnikan ninu agọ́ ajọ
nigbati o ba wọle lati ṣètutu ninu ibi
mimọ́, titi yio fi jade, ti o si ti ṣètutu fun
ara rẹ̀, ati fun ile rẹ̀, ati fun gbogbo ijọ
enia Israeli.
18 Ki o si jade si ibi pẹpẹ ti mbẹ niwaju
Oluwa, ki o si ṣètutu si i; ki o si mú
ninu ẹ̀jẹ akọmalu na, ati ninu ẹ̀jẹ ewurẹ na,
ki o si fi i sara iwo pẹpẹ na yiká.
19 Ki o si fi ika rẹ̀ mú ninu ẹ̀jẹ na wọ́n
ara rẹ̀ nigba meje, ki o si wẹ̀ ẹ mọ́, ki o si
yà a simimọ́ kuro ninu aimọ́ awọn ọmọ
Israeli.
20 Nigbati o ba si pari ati ṣètutu si ibi
mimọ́, ati si agọ́ ajọ, ati pẹpẹ, ki o mú
ewurẹ alãye nì wá:
21 Ki Aaroni ki o si fi ọwọ́ rẹ̀ mejeji lé
ori ewurẹ alãye na, ki o si jẹwọ gbogbo
aiṣedede awọn ọmọ Israeli sori rẹ̀, ati gbo-
gbo irekọja wọn, ani gbogbo ẹ̀ṣẹ wọn; ki o
si fi wọn lé ori ewurẹ na, ki o si ti ọwọ́
ẹniti o yẹ rán a lọ si ijù:
22 Ki ewurẹ na ki o si rù gbogbo aiṣe-
dede wọn lori rẹ̀ lọ si ilẹ ti a kò tẹ̀dó: ki o
si jọwọ ewurẹ na lọwọ lọ sinu ijù.
23 Ki Aaroni ki o si wá sinu agọ́ ajọ,
ki o si bọ́ aṣọ ọ̀gbọ wọnni silẹ, ti o múwọ̀
nigbati o wọ̀ ibi mimọ́ lọ, ki o si fi wọn
sibẹ̀:
24 Ki o si fi omi wẹ̀ ara rẹ̀ ni ibi mimọ́
kan, ki o si mú aṣọ rẹ̀ wọ̀, ki o si jade wá,
ki o si ru ẹbọ sisun rẹ̀, ati ẹbọ sisun awọn
enia, ki o si ṣètutu fun ara rẹ̀ ati fun awọn
enia.
25 Ọrá ẹbọ ẹ̀ṣẹ nì ni ki o si sun lori pẹpẹ.
26 Ati ẹniti o jọwọ ewurẹ nì lọwọ lọ fun
Asaseli, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀
ninu omi, lẹhin eyinì ni ki o wá si ibudó.
27 Ati akọmalu nì fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati
ewurẹ nì fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ẹ̀jẹ ẹyiti a múwa lati
fi ṣetutu ni ibi mimọ́, ni ki ẹnikan ki o mú
jade lọ sẹhin ode ibudó; ki nwọn ki o si
sun awọ wọn, ati ẹran wọn, ati igbẹ́ wọn
ninu iná.
28 Ati ẹniti o sun wọn ni ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀,
ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, lẹhin eyinì ni
ki o wá si ibudó.
29 Eyi ni ki o si ma ṣe ìlana lailai fun
nyin: pe li oṣù keje, li ọjọ́ kẹwa oṣù, ni ki
ẹnyin ki o pọ́n ọkàn nyin loju, ki ẹnyin
má si ṣe iṣẹ kan rára, iba ṣe ibilẹ, tabi
alejò ti nṣe atipo lãrin nyin:
30 Nitoripe li ọjọ́ na li a o ṣètutu fun
nyin, lati wẹ̀ nyin mọ́; ki ẹnyin ki o le
mọ́ kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ nyin niwaju
Oluwa.
31 On o jẹ́ ọjọ́ isimi fun nyin, ki ẹnyin

Digitized by Google

ki o si pọ́n ọkàn nyin loju, nipa ìlana
titilai.
32 Ati alufa na, ẹniti a o ta oróro si li
ori, ati ẹniti a o yàsimimọ́ si iṣẹ-alufa dipò
baba rẹ̀, on ni ki o ṣètutu na, ki o si mú
aṣọ ọ̀gbọ wọnni wọ̀, ani aṣọ mimọ́ wọnni:
33 Ki o si ṣètutu si ibi mimọ́, ki o si
ṣètutu si agọ́ ajọ, ati si pẹpẹ; ki o si ṣètutu
fun awọn alufa, ati fun gbogbo ijọ enia.
34 Ki eyi ki o si jẹ́ ìlana titilai fun nyin,
lati ṣètutu fun awọn ọmọ Israeli nitori ẹ̀ṣẹ
wọn gbogbo lẹ̃kan li ọdún. O si ṣe bi
OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

## ORI 17.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun Aaroni, ati fun awọn ọmọ
rẹ̀, ati fun gbogbo awọn ọmọ Israeli, ki o
si wi fun wọn pe; Eyi li ohun ti OLUWA
ti palaṣẹ, wipe,
3 Ẹnikẹni ti iṣe enia ile Israeli, ti o ba
pa akọmalu tabi ọdọ-agutan, tabi ewurẹ,
ninu ibudó, tabi ti o pa a lẹhin ibudó,
4 Ti kò si mú u wá si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ,
lati ru u li ẹbọ si OLUWA niwaju agọ́
OLUWA: a o kà ẹ̀jẹ si ọkọnrin na lọrùn, o
ta ẹ̀jẹ silẹ; ọkọnrin na li a o si ke kuro
ninu awọn enia rẹ̀:
5 Nitori idí eyi pe, ki awọn ọmọ Israeli
ki o le ma mú ẹbọ wọn wá, ti nwọn ru ni
oko gbangba, ani ki nwọn ki o le mú u tọ̀
OLUWA wá, si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, sọdọ alufa,
ki o si ru wọn li ẹbọ alafia si OLUWA.
6 Ki alufa ki o si bù ẹ̀jẹ na wọ́n ori pẹpẹ
OLUWA li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, ki o si sun ọrá
na fun õrùn didún si OLUWA.
7 Ki nwọn ki o má si ṣe ru ẹbọ wọn si
obukọ mọ́, ti nwọn ti ntọ̀ lẹhin ṣe àgbere.
Eyi ni yio ma ṣe ìlana lailai fun wọn ni
iran-iran wọn.
8 Ki iwọ ki o si wi fun wọn, Ẹnikẹni
ninu ile Israeli, tabi ninu alejò ti nṣe atipo
ninu wọn, ti o ru ẹbọ sisun tabi ẹbọ kan,
9 Ti kò si mú u wá si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ,
lati ru u si OLUWA; ani ọkọnrin na li a o
ke kuro ninu awọn enia rẹ̀.
10 Ati ẹnikẹni ninu ile Israeli, tabi ninu
alejò ti nṣe atipo ninu wọn, ti o ba jẹ ẹ̀jẹ-
kẹ̀jẹ; ani emi o kọ oju mi si ọkàn na ti o
jẹ ẹ̀jẹ, emi o si ke e kuro ninu awọn enia rẹ̀.
11 Nitoripe ẹmi ara mbẹ ninu ẹ̀jẹ: emi
si ti fi i fun nyin lati ma fi ṣètutu fun ọkàn
nyin lori pẹpẹ nì: nitoripe ẹ̀jẹ ni iṣe ètutu
fun ọkàn.
12 Nitorina ni mo ṣe wi fun awọn ọmọ
Israeli pe, Ọkàn kan ninu nyin kò gbọdọ
jẹ ẹ̀jẹ, bẹ̃li alejò kan ti nṣe atipo ninu nyin
kò gbọdọ jẹ ẹ̀jẹ.
13 Ati ẹnikẹni ninu awọn ọmọ Israeli,
tabi ninu awọn alejò ti nṣe atipo ninu wọn,
ti nṣe ọdẹ ti o si mú ẹranko tabi ẹiyẹ ti a
ba jẹ; ani ki o ro ẹ̀jẹ rẹ̀ dànu, ki o si fi
erupẹ bò o.
14 Nitoripe ẹmi gbogbo ara ni, ẹ̀jẹ rẹ̀ ni
ẹmi rẹ̀: nitorina ni mo ṣe wi fun awọn ọmọ
Israeli pe, Ẹnyin kò gbọdọ jẹ ẹ̀jẹ ẹrankẹran:
nitoripe ẹ̀jẹ li ẹmi ara gbogbo: ẹnikẹni ti o
ba jẹ ẹ li a o ke kuro.
15 Ati gbogbo ọkàn ti o ba jẹ ẹran ti o
tikara rẹ̀ kú, tabi eyiti a fàya, iba ṣe ọkan
ninu awọn ibilẹ, tabi alejò, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀,
ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́
titi di aṣalẹ: nigbana li on o mọ́.
16 Ṣugbọn bi kò ba fọ̀ wọn, tabi ti kò si
wẹ̀ ara rẹ̀; njẹ on o rù ẹ̀ṣẹ rẹ̀.

## ORI 18.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.
3 Ẹnyin kò gbọdọ hùwa bi ìwa ilẹ Egipti
nibiti ẹnyin ti ngbé: ẹnyin kò si gbọdọ
hùwa ìwa ilẹ Kenaani, nibiti emi o mú
nyin lọ: bẹ̃li ẹnyin kò gbọdọ rìn nipa
ìlana wọn.
4 Ki ẹnyin ki o ma ṣe ofin mi, ki ẹnyin
si ma pa ìlana mi mọ́, lati ma rìn ninu
wọn: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.
5 Ẹnyin o si ma pa ìlana mi mọ́, ati ofin
mi: eyiti bi enia ba ṣe, on o ma yè ninu
wọn: Emi li OLUWA.
6 Ẹnikẹni kò gbọdọ sunmọ ẹnikan ti iṣe
ibatan rẹ̀ lati tú ìhoho rẹ̀: Emi li OLUWA.
7 Ìhoho baba rẹ, tabi ìhoho iya rẹ, ni
iwọ kò gbọdọ tú: iya rẹ ni iṣe; iwọ kò
gbọdọ tú ìhoho rẹ̀.
8 Ìhoho aya baba rẹ ni iwọ kò gbọdọ tú:
ìhoho baba rẹ ni.
9 Ìhoho arabirin rẹ, ọmọ baba rẹ, tabi
ọmọ iya rẹ, ti a bi ni ile, tabi ti a bi li ode,
ani ìhoho wọn ni iwọ kò gbọdọ tú.
10 Ìhoho ọmọbirin ọmọ rẹ ọkọnrin, tabi
ti ọmọbirin ọmọ rẹ obirin, ani ìhoho wọn
ni iwọ kò gbọdọ tú: nitoripe ìhoho ara rẹ
ni nwọn.
11 Ìhoho ọmọbirin aya baba rẹ, ti a bi
lati inu baba rẹ wá, arabirin rẹ ni, iwọ kò
gbọdọ tú ìhoho rẹ̀.
12 Iwọ kò gbọdọ tú ìhoho arabirin baba
rẹ: ibatan baba rẹ ni.
13 Iwọ kò gbọdọ tú ìhoho arabirin iya
rẹ: nitoripe ibatan iya rẹ ni.

Digitized by Google

14 Iwọ kò gbọdọ tú ìhoho arakọnrin baba rẹ, iwọ kò gbọdọ sunmọ aya rẹ̀: arabirin baba rẹ ni.

15 Iwọ kò gbọdọ tú ìhoho aya ọmọ rẹ: nitoripe aya ọmọ rẹ ni iṣe; iwọ kò gbọdọ tú ìhoho rẹ̀.

16 Iwọ kò gbọdọ tú ìhoho aya arakọnrin rẹ: ìhoho arakọnrin rẹ ni.

17 Iwọ kò gbọdọ tú ìhoho obirin ati ti ọmọbirin rẹ̀; bẽni iwọ kò gbọdọ fẹ ọmọbirin ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, tabi ọmọbirin ọmọ rẹ̀ obirin, lati tú ìhoho wọn; nitoripe ibatan ni nwọn: ohun buburu ni.

18 Bẽni iwọ kò gbọdọ fẹ́ arabirin aya rẹ li aya, lati bà a ninu jẹ́, lati tú ìhoho rẹ̀, pẹlu rẹ̀ nigbati o wà lãye.

19 Ati pẹlu iwọ kò gbọdọ sunmọ obirin kan lati tú u ni ìhoho, ni ìwọn igbati a yà a sapakan nitori aimọ́ rẹ̀.

20 Pẹlupẹlu iwọ kò gbọdọ bá aya ẹnikeji rẹ dàpọ lati bà ara rẹ jẹ́ pẹlu rẹ̀.

21 Iwọ kò si gbọdọ fi irú-ọmọ rẹ kan fun Moleki, bẽni iwọ kò gbọdọ bà orukọ Ọlọrun rẹ jẹ́: Emi li OLUWA.

22 Iwọ kò gbọdọ bá ọkọnrin dápọ bi obirin: irira ni.

23 Bẽni iwọ kò gbọdọ bá ẹranko kan dàpọ, lati fi i bà ara rẹ jẹ́: bẽni obirin kan kò gbọdọ duro niwaju ẹranko kan lati dubulẹ tì i: idaru dàpọ ni.

24 Ẹ máṣe bà ara nyin jẹ́ ninu gbogbo nkan wọnyi: nitoripe ninu gbogbo nkan wọnyi li awọn orilẹ-ède, ti mo lé jade niwaju nyin dibajẹ́:

25 Ilẹ na si dibajẹ́: nitorina ni mo ṣe bẹ̀ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ wò lori rẹ̀, ilẹ tikararẹ̀ si bì awọn olugbé rẹ̀ jade.

26 Nitorina ni ki ẹnyin ki o ṣe ma pa ìlana ati ofin mi mọ́, ki ẹnyin ki o máṣe ṣe ọkan ninu irira wọnyi; tabi ẹnikan ninu ibilẹ nyin, tabi alejò ti nṣe atipo ninu nyin:

27 Nitoripe gbogbo irira wọnyi li awọn ọkọnrin ilẹ na ṣe, ti o ti wà ṣaju nyin, ilẹ na si dibajẹ́;

28 Ki ilẹ na ki o má ba bì nyin jade pẹlu, nigbati ẹnyin ba bà a jẹ́, bi o ti bì awọn orilẹ-ède jade, ti o ti wà ṣaju nyin.

29 Nitoripe ẹnikẹni ti o ba ṣe ọkan ninu irira wọnyi, ani ọkàn wọnni ti o ba ṣe wọn li a o ke kuro lãrin awọn enia wọn.

30 Nitorina ni ki ẹnyin ki o pa aṣẹ mi mọ́, ki ẹnyin ki o máṣe ọkan ninu irira wọnyi, ti nwọn ti ṣe ṣaju nyin, ki ẹnyin ki o má si bà ara nyin jẹ́ ninu rẹ̀: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.

## ORI 19.

OLUWA si sọ fun Mose pe,

2 Sọ fun gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli, ki o si wi fun wọn pe, Ki ẹnyin ki o jẹ́ mimọ́: nitoripe Emi OLUWA Ọlọrun nyin jẹ́ mimọ́.

3 Ki olukuluku nyin ki o bẹ̀ru iya rẹ̀, ati baba rẹ̀, ki o si ma pa ọjọ́ isimi mi mọ́: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.

4 Ẹ máṣe yipada si ere, bẽni ki ẹnyin má si ṣe ṣe oriṣa didà fun ara nyin: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.

5 Bi ẹnyin ba si ru ẹbọ alafia si OLUWA, ki ẹnyin ki o ru u ki ẹ le di ẹni itẹwọgbà.

6 Li ọjọ́ ti ẹnyin ru ẹbọ na ni ki a jẹ ẹ, ati ni ijọ́ keji: bi ohun kan ba si kù ninu rẹ̀ titi di ijọ́ kẹta, ninu iná ni ki a sun u.

7 Bi a ba si jẹ ninu rẹ̀ rára ni ijọ́ kẹta, irira ni; ki yio dà:

8 Nitorina ẹniti o ba jẹ ẹ ni yio rù ẹ̀ṣẹ rẹ̀, nitoriti o bà ohun mimọ́ OLUWA jẹ́: ọkàn na li a o si ke kuro ninu awọn enia rẹ̀.

9 Ati nigbati ẹnyin ba nṣe ikore ilẹ nyin, iwọ kò gbọdọ ṣà igun oko rẹ li aṣatán, bẽni iwọ kò gbọdọ pa ẽṣẹ́ ikore rẹ.

10 Iwọ kò si gbọdọ pèṣẹ́ ọgbà-àjara rẹ, bẽni iwọ kò gbọdọ ká gbogbo àjara ọgbà-àjara rẹ; ki iwọ ki o fi wọn silẹ fun awọn talaka ati alejò: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.

11 Ẹnyin kò gbọdọ jale, bẽli ẹnyin kò gbọdọ ṣe alaiṣõtọ, bẽli ẹnyin kò gbọdọ ṣeké fun ara nyin.

12 Ẹnyin kò si gbọdọ fi orukọ mi bura eké, bẽni iwọ kò gbọdọ bà orukọ Ọlọrun rẹ jẹ́: Emi li OLUWA.

13 Iwọ kò gbọdọ rẹ́ ẹnikeji rẹ jẹ, bẽni iwọ kò gbọdọ jẹ haramù: owo ọ̀ya alagbaṣe kò gbọdọ sùn ọdọ rẹ titi di owurọ̀.

14 Iwọ kò gbọdọ bú aditi, tabi ki o fi ohun idugbolu siwaju afọju, ṣugbọn ki iwọ ki o bẹ̀ru Ọlọrun rẹ: Emi li OLUWA.

15 Ẹnyin kò gbọdọ ṣe aiṣododo ni idajọ: iwọ kò gbọdọ gbè talaka, bẽni iwọ kò gbọdọ ṣe ojusaju alagbara: li ododo ni ki iwọ ki o mã ṣe idajọ ẹnikeji rẹ.

16 Iwọ kò gbọdọ lọ soke lọ sodo bi olofófo lãrin awọn enia rẹ: bẽni iwọ kò gbọdọ ró tì ẹ̀jẹ ẹnikeji rẹ: Emi li OLUWA.

17 Iwọ kò gbọdọ korira arakọnrin rẹ li ọkàn rẹ: ki iwọ ki o bá ẹnikeji rẹ wi, ki iwọ ki o máṣe jẹbi nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀.

18 Iwọ kò gbọdọ gbẹsan, bẽni ki o máṣe ikùnsinu si awọn ọmọ enia rẹ, ṣugbọn

Digitized by Google

ki iwọ ki o fẹ́ ẹnikeji rẹ bi ara rẹ: Emi li
OLUWA.
19 Ki ẹnyin ki o pa ìlana mi mọ́. Iwọ
kò gbọdọ jẹ ki ẹranọsin rẹ ki o ba onirũru
dàpọ: iwọ kò gbọdọ fọ́n darudàpọ irugbìn
si oko rẹ: bẽli aṣọ ti a fi ọ̀gbọ ati kubusu
wun pọ̀ kò gbọdọ kan ara rẹ.
20 Ati ẹnikẹni ti o ba bá obirin dàpọ, ti
iṣe ẹrú, ti a fẹ́ fun ọkọ, ti a kò ti ràpada
rára, ti a kò ti sọ di omnira; ọ̀ran ìna ni;
ki a máṣe pa wọn, nitoriti obirin na ki iṣe
omnira.
21 Ki ọkọnrin na ki o si mú ẹbọ ẹbi rẹ̀
wá fun OLUWA, si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, ani
àgbo kan fun ẹbọ ẹbi.
22 Ki alufa ki o si fi àgbo ẹbọ ẹbi ṣètutu
fun u niwaju OLUWA nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o da:
a o si dari ẹ̀ṣẹ ti o da jì i.
23 Ati nigbati ẹnyin o ba si dé ilẹ na, ti
ẹnyin o si gbìn onirũru igi fun onjẹ, ni-
gbana ni ki ẹnyin kà eso rẹ̀ si alaikọlà: li
ọdún mẹta ni ki o jasi bi alaikọlà fun
nyin; ki a máṣe jẹ ẹ.
24 Ṣugbọn li ọdún kẹrin, gbogbo eso rẹ̀
na ni yio jẹ́ mimọ́, si iyìn OLUWA.
25 Ati li ọdún karun ni ki ẹnyin ki o
ma jẹ ninu eso rẹ̀, ki o le ma mú ibisi rẹ̀
wá fun nyin: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.
26 Ẹnyin kò gbọdọ jẹ ohun kan ti on ti
ẹ̀jẹ: bẽli ẹnyin kò gbọdọ ṣe ifaiya, tabi ṣe
akiyesi ìgba.
27 Ẹnyin kò gbọdọ gẹ̀ ori nyin, bẽni iwọ
kò gbọdọ tọ́ irungbọn rẹ.
28 Ẹnyin kò gbọdọ sín gbẹ́rẹ kan si ara
nyin nitori okú, bẽli ẹnyin kò gbọdọ kọ
àmi kan si ara nyin: Emi li OLUWA.
29 Máṣe bà ọmọ rẹ obirin jẹ́, lati mu u
ṣe àgbere; ki ilẹ na ki o má ba di ilẹ
àgbere, ati ki ilẹ na má ba kún fun ìwabu-
buru.
30 Ki ẹnyin ki o si ma pa ọjọ́ isimi mi
mọ́, ki ẹnyin ki o si bọ̀wọ fun ibi mimọ́
mi: Emi li OLUWA.
31 Máṣe yipada tọ̀ awọn ti o ní ìmọ afọṣẹ,
bẽni ki ẹnyin ki o má si ṣe wá ajẹ́ kiri, lati
fi wọn bà ara nyin jẹ́: Emi li OLUWA
Ọlọrun nyin.
32 Ki iwọ ki o si dide duro niwaju ori-
ewú, ki o si bọ̀wọ fun oju arugbo, ki o si
bẹ̀ru Ọlọrun rẹ: Emi li OLUWA.
33 Ati bi alejò kan ba nṣe atipo pẹlu rẹ
ni ilẹ nyin, ẹnyin kò gbọdọ ni i lara.
34 Ki alejò ti mbá nyin gbé ki o jasi fun
nyin bi ibilẹ, ki iwọ ki o si fẹ́ ẹ bi ara rẹ;
nitoripe ẹnyin ti ṣe alejò ni ilẹ Egipti:
Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.
35 Ẹnyin kò gbọdọ ṣe aiṣododo ni idajọ,
ni ìwọn ọpá, ni òṣuwọn iwuwo, tabi ni
òṣuwọn oninu.
36 Oṣuwọn otitọ, òṣuwọn iwuwo otitọ,
òṣuwọn efa otitọ, ati òṣuwọn hini otitọ, ni
ki ẹnyin ki o ní: Emi li OLUWA Ọlọrun
nyin, ti o mú nyin lati ilẹ Egipti jade wá.
37 Nitorina ni ki ẹnyin ki o si ma kiyesi
gbogbo ìlana mi, ati si gbogbo idajọ mi, ki
ẹnyin si ma ṣe wọn: Emi li OLUWA.

## ORI 20.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Iwọ o si sọ fun awọn ọmọ Israeli pe,
Ẹnikẹni ninu awọn ọmọ Israeli, tabi ninu
awọn alejò ti nṣe atipo ni Israeli, ti o ba fi
ninu irú-ọmọ rẹ̀ fun Moleki; pipa ni ki a
pa a: ki awọn enia ilẹ na ki o sọ ọ li okuta
pa.
3 Emi o si kọju mi si ọkọnrin na, emi o
si ke e kuro lãrin awọn enia rẹ̀; nitoriti o
fi ninu irú-ọmọ rẹ̀ fun Moleki, lati sọ ibi
mimọ́ mi di aimọ́, ati lati bà orukọ mimọ
mi jẹ́.
4 Bi awọn enia ilẹ na ba si mú oju wọn
kuro lara ọkọnrin na, nigbati o ba fi ninu
irú-ọmọ rẹ̀ fun Moleki, ti nwọn kò si pa a:
5 Nigbana li emi o kọju si ọkọnrin na,
ati si idile rẹ̀, emi o si ke e kuro, ati gbogbo
awọn ti o ṣe àgbere tọ̀ ọ lẹhin, lati ma ṣe
àgbere tọ̀ Moleki lẹhin, lãrin awọn enia wọn.
6 Ati ọkàn ti o ba yipada tọ̀ awọn ti o
ní ìmọ afọṣẹ, ati ajẹ́, lati ṣe àgbere tọ̀ wọn
lẹhin, ani emi o kọju mi si ọkàn na, emi o
si ke e kuro lãrin awọn enia rẹ̀.
7 Nitorina ẹnyin yà ara nyin simimọ́,
ki ẹnyin ki o si jẹ́ mimọ́: nitoripe Emi li
OLUWA Ọlọrun nyin.
8 Ki ẹnyin ki o si ma pa ìlana mi mọ́, ki
enyin si ma ṣe wọn: Emi li OLUWA ti nyà
nyin simimọ́.
9 Ẹnikẹni ti o ba fi baba tabi iya rẹ̀ ré,
pipa li a o pa a: o fi baba on iya rẹ̀ ré; ẹ̀jẹ
rẹ̀ wà lori rẹ̀.
10 Ati ọkọnrin na ti o bá aya ọkọnrin
miran ṣe panṣaga, ani on ti o bá aya ẹni-
keji rẹ̀ ṣe panṣaga, panṣaga ọkọnrin ati
panṣaga obirin li a o pa nitõtọ.
11 Ati ọkọnrin ti o bá aya baba rẹ̀ dàpọ,
o tú ìhoho baba rẹ̀: pipa li a o pa awọn
mejeji; ẹ̀jẹ wọn yio wà lori wọn.
12 Ọkọnrin kan ti o ba bá aya ọmọ rẹ̀
dàpọ, pipa ni ki a pa awọn mejeji: nwọn ṣe
rudurudu; ẹ̀jẹ wọn wà lori wọn.
13 Ati ọkọnrin ti o ba bá ọkọnrin dàpọ,
bi ẹni ba obirin dàpọ, awọn mejeji li o ṣe



Digitized by Google

ohun irira: pipa li a o pa wọn; ẹ̀jẹ wọn yio wà lori wọn.

14 Ati ọkọnrin ti o ba fẹ́ obirin ati iya rẹ̀, ìwabuburu ni: iná li a o fi sun wọn, ati on ati awọn; ki ìwabuburu ki o má ṣe sí lãrin nyin.

15 Ati ọkọnrin ti o ba bá ẹranko dàpọ, pipa ni ki a pa a: ki ẹnyin ki o si pa ẹranko na.

16 Bi obirin kan ba si sunmọ ẹranko kan, lati dubulẹ tì i, ki iwọ ki o pa obirin na, ati ẹranko na: pipa ni ki a pa wọn; ẹ̀jẹ wọn yio wà lori wọn.

17 Ati bi ọkọnrin kan ba fẹ́ arabirin rẹ̀, ọmọbirin baba rẹ̀, tabi ọmọbirin iya rẹ̀, ti o si ri ìhoho rẹ̀, ti on si ri ìhoho rẹ̀; ohun buburu ni; a o si ke wọn kuro loju awọn enia wọn: o tú ìhoho arabirin rẹ̀; on o rù ẹ̀ṣẹ rẹ̀.

18 Ati bi ọkọnrin kan ba bá obirin dàpọ ti o ní ohun obirin rẹ̀ lara, ti o ba si tú u ni ìhoho; o tú isun rẹ̀ ni ìhoho, obirin na si fi isun ẹ̀jẹ rẹ̀ hàn: awọn mejeji li a o si ke kuro lãrin awọn enia wọn.

19 Iwọ kò si gbọdọ tú ìhoho arabirin iya rẹ, tabi ti arabirin baba rẹ: nitoripe o tú ìhoho ibatan rẹ̀: nwọn o rù ẹ̀ṣẹ wọn.

20 Bi ọkọnrin kan ba si bá aya arakọnrin õbi rẹ̀ dàpọ, o tú ìhoho arakọnrin õbi rẹ̀: nwọn o rù ẹ̀ṣẹ wọn; nwọn o kú li ailọmọ.

21 Bi ọkọnrin kan ba si fẹ́ aya arakọnrin rẹ̀, ohun-aimọ́ ni: o tú ìhoho arakọnrin rẹ̀; nwọn o jẹ́ alailọmọ.

22 Nitorina li ẹnyin o ṣe ma pa gbogbo ìlana mi mọ́, ati gbogbo idajọ mi, ki ẹnyin si ma ṣe wọn: ki ilẹ na, ninu eyiti mo mú nyin wá tẹ̀dó si, ki o má ṣe bì nyin jade.

23 Ẹnyin kò si gbọdọ rìn ninu ìlana orilẹ-ède, ti emi lé jade kuro niwaju nyin: nitoriti nwọn ṣe gbogbo wọnyi, nitorina ni mo ṣe korira wọn.

24 Ṣugbọn emi ti wi fun nyin pe, Ẹnyin o ní ilẹ wọn, ati pe emi o fi i fun nyin lati ní i, ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin, ti o yà nyin sọ̀tọ kuro ninu awọn orilẹ-ède.

25 Nitorina ki ẹnyin ki o fi ìyatọ sãrin ẹranko mimọ́ ati alaimọ́, ati sãrin ẹiyẹ alaimọ́ ati mimọ́: ki ẹnyin ki o má si ṣe fi ẹranko, tabi ẹiyẹ, tabi ohunkohun alãye kan ti nrakò lori ilẹ, ti mo ti yàsọ̀tọ fun nyin bi alaimọ́, sọ ọkàn nyin di irira.

26 Ki ẹnyin ki o si jẹ́ mimọ́ fun mi: nitoripe mimọ́ li Emi OLUWA, mo si ti yà nyin sọ̀tọ kuro ninu awọn orilẹ-ède, ki ẹnyin ki o le jẹ́ ti emi.

27 Ọkọnrin pẹlu tabi obirin ti o ní ìmọ afọ̀ṣẹ, tabi ti iṣe ajẹ́, pipa ni ki a pa a: okuta ni ki a fi sọ wọn pa: ẹ̀jẹ wọn yio wà lori wọn.

## ORI 21.

OLUWA si sọ fun Mose pe, Sọ fun awọn alufa, awọn ọmọ Aaroni, ki o si wi fun wọn pe, Ẹnikẹni ninu awọn enia rẹ̀ kò gbọdọ di alaimọ́ nitori okú.

2 Bikoṣe fun ibatan rẹ̀ ti o sunmọ ọ, eyinì ni, iya rẹ̀, ati baba rẹ̀, ati ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, ati ọmọ rẹ̀ obirin, ati arakọnrin rẹ̀;

3 Ati arabirin rẹ̀ ti iṣe wundia, ti o wà lọdọ rẹ̀, ti kò ti ilí ọkọ, nitori rẹ̀ ni ki o di alaimọ́.

4 Ṣugbọn on kò gbọdọ ṣe ara rẹ̀ li aimọ́, lati bà ara rẹ̀ jẹ́, olori kan sa ni ninu awọn enia rẹ̀.

5 Nwọn kò gbọdọ dá ori wọn fá, bẹ̃ni nwọn kò gbọdọ tọ́ irungbọn wọn, tabi singbẹrẹ kan si ara wọn.

6 Ki nwọn ki o si jasi mimọ́ fun Ọlọrun wọn, ki nwọn ki o má si ṣe bà orukọ Ọlọrun wọn jẹ́: nitoripe ẹbọ OLUWA ti a fi ina ṣe, ati àkara Ọlọrun wọn, ni nwọn fi nrubọ: nitorina ni ki nwọn ki o jẹ́ mimọ́.

7 Nwọn kò gbọdọ fẹ́ aya ti iṣe àgbere, tabi ẹni ibàjẹ́; bẹ̃ni nwọn kò gbọdọ fẹ́ obirin ti a ti ọdọ ọkọ rẹ̀ kọsilẹ: nitoripe mimọ́ li on fun Ọlọrun rẹ̀.

8 Nitorina ki ẹnyin ki o yà a simimọ́; nitoriti o nrubọ àkara Ọlọrun rẹ: yio jẹ́ mimọ́ si ọ: nitoripe mimọ́ li Emi OLUWA, ti o yà nyin simimọ́.

9 Ati bi ọmọbirin alufa kan, ba fi iṣẹ àgbere bà ara rẹ jẹ́, o bà baba rẹ̀ jẹ́: iná li a o da sun u.

10 Ati olori alufa ninu awọn arakọnrin rẹ̀, ori ẹniti a dà oróro itasori si, ti a si yàsọtọ lati ma wọ̀ aṣọ wọnni, ki o máṣe ṣi ibori rẹ̀, tabi ki o fà aṣọ rẹ̀ ya;

11 Ki o má si ṣe wọle tọ̀ okú kan lọ, bẹ̃ni ki o máṣe sọ ara rẹ̀ di alaimọ́ nitori baba rẹ̀, tabi nitori iya rẹ̀;

12 Bẹ̃ni ki o máṣe jade kuro ninu ibi mimọ́, bẹ̃ni ki o máṣe bà ibi mimọ́ Ọlọrun rẹ̀ jẹ́, nitoripe adé oróro itasori Ọlọrun rẹ̀ mbẹ lori rẹ̀: Emi li OLUWA.

13 Wundia ni ki o fẹ́ li aya fun ara rẹ̀.

14 Opó, tabi obirin ikọsilẹ, tabi ẹni-ibàjẹ́, tabi panṣaga, wọnyi ni on kò gbọdọ fẹ́: bikoṣe wundia ni ki o fẹ́ li aya lati inu awọn enia rẹ̀.

15 Bẹ̃ni ki o máṣe bà irú-ọmọ rẹ̀ jẹ́ ninu

Digitized by Google

awọn enia rẹ̀: nitoripe Emi li OLUWA ti o yà a simimọ́.

16 OLUWA si sọ fun Mose pe,

17 Sọ fun Aaroni pe, Ẹnikẹni ninu irú-ọmọ rẹ ni iran-iran wọn, ti o ní àbukun kan, ki o máṣe sunmọtosi lati rubọ àkara Ọlọrun rẹ̀.

18 Nitoripe gbogbo ọkọnrin ti o ní àbukun, ki o máṣe sunmọtosi: ọkọnrin afọju, tabi amọkun, tabi arẹ́mu, tabi ohun kan ti o leke,

19 Tabi ọkọnrin ti iṣe aṣẹ́sẹ̀, tabi aṣẹ́wọ,

20 Tabi abuké, tabi arará, tabi ẹniti o ní àbukun kan li oju rẹ̀, tabi ti o ní ekuru, tabi ipẹ́, tabi ti kóro rẹ̀ fọ́:

21 Ẹnikẹni ti o ní àbukun ninu irú-ọmọ Aaroni alufa kò gbọdọ sunmọtosi lati ru ẹbọ OLUWA ti a fi iná ṣe: on li àbukun; kò gbọdọ sunmọtosi lati rubọ àkara Ọlọrun rẹ̀.

22 On o ma jẹ àkara Ọlọrun rẹ̀, ti mimọ́ julọ ati ti mimọ́.

23 Kìki on ki yio wọ̀ inu aṣọ-ikele nì lọ, bẽni ki o máṣe sunmọ pẹpẹ, nitoriti on ní àbukun: ki on ki o máṣe bà ibi mimọ́ mi jẹ́: nitori Emi li OLUWA ti o yà wọn simimọ́.

24 Mose si wi fun Aaroni, ati fun awọn ọmọ rẹ̀, ati fun gbogbo awọn ọmọ Israeli.

## ORI 22.

OLUWA si sọ fun Mose pe,

2 Sọ fun Aaroni ati fun awọn ọmọ rẹ̀ pe, ki nwọn ki o yà ara wọn sọ̀tọ kuro ninu ohun mimọ́ awọn ọmọ Israeli, ki nwọn ki o má si ṣe bà orukọ mimọ́ mi jẹ́ ninu ohun wọnni, ti nwọn yàsimimọ́ fun mi: Emi li OLUWA,

3 Wi fun wọn pe, Ẹnikẹni ninu gbogbo irú-ọmọ nyin ninu awọn iran nyin, ti o ba sunmọ ohun mimọ́, ti awọn ọmọ Israeli yàsimimọ́ fun OLUWA, ti o ní aimọ́ rẹ̀ lara rẹ̀, ọkàn na li a o ke kuro niwaju mi: Emi li OLUWA.

4 Ẹnikẹni ninu irú-ọmọ Aaroni ti iṣe adẹtẹ, tabi ti o ní isun; ki o máṣe jẹ ninu ohun mimọ́, titi on o fi di mimọ́. Ati ẹnikẹni ti o farakàn ohun ti iṣe aimọ́, bi okú, tabi ọkọnrin ti ohun-irú nti ara rẹ̀ jade;

5 Tabi ẹniti o ba farakàn ohun ti nrakò kan, ti yio sọ ọ di aimọ́, tabi enia kan ti yio sọ ọ di aimọ́, irú aimọ́ ti o wù ki o ní;

6 Ọkàn ti o ba farakàn ọkan ninu irú ohun bẽ ki o jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ, ki o má si ṣe jẹ ninu ohun mimọ́, bikoṣepe o ba fi omi wẹ̀ ara rẹ̀.

7 Nigbati õrùn ba si wọ̀, on o di mimọ́; lẹhin eyinì ki o si ma jẹ ninu ohun mimọ́, nitoripe onjẹ rẹ̀ ni.

8 On kò gbọdọ jẹ ẹran ti o kú fun ara rẹ̀, tabi eyiti ẹranko fàya, lati fi i bà ara rẹ̀ jẹ́: Emi li OLUWA.

9 Nitorina ki nwọn ki o ma pa ìlana mi mọ́, ki nwọn ki o máṣe rù ẹ̀ṣẹ nitori rẹ̀, nwọn a si kú nitorina, bi nwọn ba bà a jẹ́: Emi li OLUWA ti o yà wọn simimọ́.

10 Alejò kan kò gbọdọ jẹ ninu ohun mimọ́: alabagbé alufa, tabi alagbaṣe kò gbọdọ jẹ ninu ohun mimọ́ na.

11 Ṣugbọn bi alufa ba fi owo rẹ̀ rà ẹnikan, ki o jẹ ninu rẹ̀; ẹniti a si bi ninu ile rẹ̀, ki nwọn ki o ma jẹ ninu onjẹ rẹ̀.

12 Bi ọmọbirin alufa na ba si ní alejò kan li ọkọ, obirin na kò le jẹ ninu ẹbọ fifì ohun mimọ́.

13 Ṣugbọn bi ọmọbirin alufa na ba di opó, tabi ẹni-ikọsilẹ, ti kò si lí ọmọ, ti o si pada wá si ile baba rẹ̀, bi ìgba ewe rẹ̀, ki o ma jẹ ninu onjẹ baba rẹ̀: ṣugbọn alejò kan kò gbọdọ jẹ ninu rẹ̀.

14 Bi ẹnikan ba si jẹ ninu ohun mimọ́ li aimọ̀, njẹ ki o fi idamarun rẹ̀ lé e, ki o si fi i fun alufa pẹlu ohun mimọ́ na.

15 Nwọn kò si gbọdọ bà ohun mimọ́ awọn ọmọ Israeli jẹ́, ti nwọn mú fun OLUWA wa:

16 Tabi lati jẹ ki nwọn ki o rù aiṣedede ti o mú ẹbi wá, nigbati nwọn ba njẹ ohun mimọ́ wọn: nitoripe Emi li OLUWA ti o yà wọn simimọ́.

17 OLUWA si sọ fun Mose pe,

18 Sọ fun Aaroni, ati fun awọn ọmọ rẹ̀, ati fun gbogbo awọn ọmọ Israeli, ki o si wi fun wọn pe, Ẹnikẹni ninu ile Israeli, tabi ninu awọn alejò ni Israeli, ti o ba fẹ́ ru ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ nitori ẹjẹ́ wọn gbogbo, ati nitori ẹbọ rẹ̀ atinuwá gbogbo, ti nwọn nfẹ́ ru si OLUWA fun ẹbọ sisun;

19 Ki o le dà fun nyin, akọ alailabùkun ni ki ẹnyin ki o fi ru u, ninu malu, tabi ninu agutan, tabi ninu ewurẹ.

20 Ṣugbọn ohunkohun ti o ní abùkun, li ẹnyin kò gbọdọ múwa: nitoripe ki yio dà fun nyin.

21 Ati ẹnikẹni ti o ba ru ẹbọ alafia si OLUWA, lati san ẹjẹ́, tabi ẹbọ ifẹ́-atinuwá ni malu tabi agutan, ki o pé ki o ba le dà; ki o máṣe sí abùkun kan ninu rẹ̀.

22 Afọju, tabi fifàya, tabi eyiti a palara, tabi elegbo, elekuru, tabi oni-ipẹ́, wọnyi li

Digitized by Google

ẹnyin kò gbọdọ fi rubọ si OLUWA, bẹ̃ni
ẹnyin kò gbọdọ fi ninu wọn ṣe ẹbọ ti a fi
iná ṣe si OLUWA lori pẹpẹ.
23 Ibaṣe akọmalu tabi ọdọ-agutan ti o
ní ohun ileke kan, tabi ohun abùkun kan,
eyinì ni ki iwọ ma fi ru ẹbọ ifẹ́-atinuwá;
ṣugbọn fun ẹjẹ́ ki yio dà.
24 Ẹnyin kò gbọdọ mú eyiti kóro rẹ̀ fọ́,
tabi ti a tẹ̀, tabi ti a ya, tabi ti a là, wá
rubọ si OLUWA; ki ẹnyin máṣe e ni ilẹ
nyin.
25 Bẹ̃ni ẹnyin kò gbọdọ ti ọwọ́ alejò
rubọ àkara Ọlọrun nyin ninu gbogbo wọnyi;
nitoripe ibàjẹ́ wọn mbẹ ninu wọn, abùkun
si mbẹ ninu wọn: nwọn ki yio dà fun nyin.
26 OLUWA si sọ fun Mose pe,
27 Nigbati a ba bi akọmalu kan, tabi
agutan kan, tabi ewurẹ kan, nigbana ni ki
o gbé ijọ meje lọdọ iya rẹ̀; ati lati ijọ́ kẹjọ
ati titi lọ on o di itẹwọgbà fun ẹbọ ti a fi
iná ṣe si OLUWA.
28 Ibaṣe abomalu tabi agutan, ẹnyin kò
gbọdọ pa a ati ọmọ rẹ̀ li ọjọ́ kanna.
29 Nigbati ẹnyin ba si ru ẹbọ ọpẹ́ si
OLUWA, ẹ ru u ki o le dà.
30 Li ọjọ́ na ni ki a jẹ ẹ; ẹnyin kò gbọ-
dọ kù silẹ ninu rẹ̀ titi di ijọ́ keji: Emi li
OLUWA.
31 Nitorina ni ki ẹnyin ki o ma pa aṣẹ
mi mọ́, ki ẹnyin si ma ṣe wọn: Emi li
OLUWA.
32 Bẹ̃ni ẹnyin kò gbọdọ bà orukọ mimọ́
mi jẹ́; bikoṣe ki a yà mi simimọ́ lãrin awọn
ọmọ Israeli: Emi li OLUWA ti nyà nyin
simimọ́,
33 Ti o mú nyin jade lati ilẹ Egipti wá,
lati ma ṣe Ọlọrun nyin: Emi li OLUWA.

## ORI 23.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, ajọ OLUWA, ti ẹnyin o pè fun
apejọ mimọ́, wọnyi li ajọ mi.
3 Ijọ́ mẹfa ni ki a ṣe iṣẹ; ṣugbọn ni ijọ́
keje li ọjọ́ isimi, apejọ mimọ́; ẹnyin kò
gbọdọ ṣe iṣẹ kan ninu rẹ̀: nitoripe ọjọ́-isimi
OLUWA ni ninu ibujoko nyin gbogbo.
4 Wọnyi li ajọ OLUWA, ani apejọ mimọ́,
ti ẹnyin o pè li akokò wọn.
5 Ni ijọ́ kẹrinla oṣù kini, li aṣalẹ, li ajọ
irekọja OLUWA.
6 Ati li ọjọ́ kẹdogun oṣù na li ajọ àkara
alaiwu si OLUWA; ijọ́ meje li ẹnyin o jẹ
àkara alaiwu.
7 Li ọjọ́ kini ki ẹnyin ki o ní apejọ
mimọ́: ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹ agbara ninu
rẹ̀.
8 Bikoṣe ki ẹnyin ki o ru ẹbọ ti a fi iná
ṣe si OLUWA ni ijọ́ meje: ni ijọ́ keje ni
apejọ mimọ́: ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹ agbara.
9 OLUWA si sọ fun Mose pe,
10 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba dé ilẹ ti mo fi
fun nyin, ti ẹnyin o si ma ṣe ikore rẹ̀, ni-
gbana ni ki ẹnyin ki o mú ìdi-ọkà kan akọ́so
ikore nyin tọ̀ alufa wá:
11 On o si fì ìdi-ọkà na niwaju OLUWA,
lati ṣe itẹwọgbà fun nyin: ni ijọ́ keji lẹhin
ọjọ́-isimi ni ki alufa ki o fì i.
12 Li ọjọ́ ti ẹnyin fì ìdi-ọkà ni ki ẹnyin
ki o rubọ akọ ọdọ-agutan ọlọdún kan alai-
labùkun fun ẹbọ sisun si OLUWA.
13 Ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀ ki o jẹ́ meji ida-
mẹwa òṣuwọn iyẹfun daradara, ti a fi oróro
pò, ẹbọ ti a fi iná ṣe ni si OLUWA fun õrun
didùn: ati ẹbọ ohun-mimu rẹ̀ ni ki o ṣe
ọtí-waini idamẹrin òṣuwọn hini.
14 Ẹnyin kò si gbọdọ jẹ àkara, tabi ọkà
yiyan, tabi ọkà tutù ninu ipẹ́, titi yio fi di
ọjọ́ na gan ti ẹnyin mú ọrẹ-ẹbọ tọ̀ Ọlorun
nyin wá: ki o si jasi ìlana titilai ni iran-
iran nyin ni ibujoko nyin gbogbo.
15 Lati ijọ́ keji lẹhin ọjọ́-isimi, ni ọjọ́ ti
ẹnyin mú ìdi-ọkà ẹbọ fifì nì wá, ki ẹnyin ki
o si kà ọjọ́-isimi meje pé;
16 Ani di ijọ́ keji lẹhin ọjọ́-isimi keje, ki
ẹnyin ki o kà ãdọta ọjọ́; ki ẹnyin ki o si
ru ẹbọ ohunjijẹ titun si OLUWA.
17 Ki ẹnyin ki o si mú lati inu ibugbé
nyin wá, ìṣu-àkara fifì meji ti idamẹwa
meji òṣuwọn: ki nwọn ki o jẹ́ ti iyẹfun
daradara, ki a fi iwukàra yan wọn akọ́so ni
nwọn fun OLUWA.
18 Pẹlu àkara na ki ẹnyin ki o si fi ọdọ-
agutan meje ọlọdún kan alailabukùn rubọ,
ati ẹgbọrọ akọmalu kan, ati àgbo meji: ki
nwọn ki o jẹ́ ẹbọ sisun si OLUWA, pẹlu ẹbọ
ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohunmimu wọn, ani
ẹbọ ti a fi iná ṣe olõrùn didùn ni si OLUWA.
19 Nigbana ni ki ẹnyin ki o fi obukọ kan
ru ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati akọ ọdọ-agutan meji ọlọdún
kan ru ẹbọ alafia.
20 Ki alufa ki o si fi wọn pẹlu àkara
àwọn akọ́so fun ẹbọ fifì niwaju OLUWA, pẹlu
ọdọ-agutan meji nì: ki nwọn ki o si jẹ́
mimọ́ si OLUWA fun alufa na.
21 Ki ẹnyin ki o si kede li ọjọ́ na gan;
ki o le jẹ́ apejọ mimọ́ fun nyin: ẹnyin kò
gbọdọ ṣe iṣẹ agbara kan: yio si ma ṣe ìlana
fun nyin titilai ni ibujoko nyin gbogbo ni
iran-iran nyin.

Digitized by Google

22 Nigbati ẹnyin ba nṣe ikore ilẹ nyin,
iwọ kò gbọdọ ṣa ẹba oko rẹ li aṣatán, bẽni
iwọ kò gbọdọ pèṣé ikore rẹ: ki iwọ ki o fi
i silẹ fun awọn talaka, ati fun alejò: Emi
li OLUWA Ọlọrun nyin.
23 OLUWA si sọ fun Mose pe,
24 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Li oṣù
keje, li ọjọ́ kini oṣù ni ki ẹnyin ki o ní isi-
mi; iranti ifunpe, apejọ mimọ́.
25 Ẹnyin kò gbọ̀dọ ṣe iṣẹ agbara kan:
bikoṣepe ki ẹnyin ki o ru ẹbọ ti a fi iná ṣe
si OLUWA.
26 OLUWA si sọ fun Mose pe,
27 Ijọ́ kẹwa oṣù keje yi ni ki o ṣe ọjọ́ ètu-
tu: ki apejọ mimọ́ wà fun nyin, ki ẹnyin ki
o si pọ́n ọkàn nyin loju, ki ẹ si ru ẹbọ ti a fi
iná ṣe si OLUWA.
28 Ẹnyin kò si gbọdọ ṣe iṣẹ kan li ọjọ́ na
yi: nitoripe ọjọ́ ètutu ni, lati ṣètutu fun
nyin niwaju OLUWA Ọlọrun nyin.
29 Nitoripe ọkànkọkàn ti kò ba pọ́n ara
rẹ̀ loju li ọjọ́ na yi, on li a o ke kuro ninu
awọn enia rẹ̀.
30 Ati ọkànkọkan ti o ba ṣe iṣẹ kan li
ọjọ́ na yi, ọkàn na li emi o run kuro lãrin
awọn enia rẹ̀.
31 Ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹkiṣẹ kan: ki o
jẹ́ ìlana titilai ni iran-iran nyin ni ibujoko
nyin gbogbo.
32 Ọjọ́-isimi ni fun nyin, ki ẹnyin ki o
si pọ́n ọkàn nyin loju: li ọjọ́ kẹsan oṣù na
li alẹ, lati alẹ dé alẹ, ni ki ẹnyin ki o ma
pa ọjọ́-isimi nyin mọ́.
33 OLUWA si sọ fun Mose pe,
34 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Ọjọ́ kẹ-
dogun oṣù keje yi li ajọ agọ́ ni ijọ́ meje si
OLUWA.
35 Li ọjọ́ kini li apejọ mimọ́: ẹnyin kò
gbọdọ ṣe iṣẹ agbara kan.
36 Ijọ́ meje ni ki ẹnyin fi ru ẹbọ ti a fi
iná ṣe si OLUWA: ni ijọ́ kẹjọ li apejọ́ mimọ́
fun nyin; ki ẹnyin ki o si ru ẹbọ ti a fi iná
ṣe si OLUWA; ọjọ́ ajọ ni; ẹnyin kò gbọdọ
ṣe iṣẹ agbara kan.
37 Wọnyi li ajọ OLUWA, ti ẹnyin o kedé
lati jẹ́ apejọ mimọ́, lati ru ẹbọ ti a fi iná ṣe
si OLUWA, ẹbọ sisun, ati ẹbọ ohunjijẹ, ẹbọ,
ati ẹbọ ohunmimu, olukuluku wọn li ọjọ́
rẹ̀:
38 Pẹlu ọjọ́-isimi OLUWA, ati pẹlu ẹ̀bun
nyin, ati pẹlu gbogbo ẹjẹ́ nyin, ati pẹlu
gbogbo ẹbọ atinuwá nyin, ti ẹnyin fi fun
OLUWA.
39 Pẹlupẹlu li ọjọ́ kẹdogun oṣù keje na,
nigbati ẹnyin ba ṣe ikore eso ilẹ tán, ki
ẹnyin ki o si ṣe ajọ si OLUWA ni ijọ́ meje:
li ọjọ́ kini ki isimi ki o wà, ati li ọjọ́ kẹjọ ki
isimi ki o wà,
40 Li ọjọ́ kini ki ẹnyin ki o si mú eso igi
daradara, imọ̀-ọpẹ, ati ẹká igi ti o bò, ati ti
igi wilo odò; ki ẹnyin ki o si ma yọ̀ niwaju
OLUWA Ọlọrun nyin ni ijọ́ meje.
41 Ki ẹnyin ki o si ma pa a mọ́ li ajọ
fun OLUWA ni ijọ́ meje li ọdún: ìlana ni
titilai ni iran-iran nyin: ki ẹnyin ki o ma
ṣe e li oṣù keje.
42 Ki ẹnyin ki o ma gbé inu agọ́ ni ijọ́
meje; gbogbo ibilẹ ni Israeli ni ki o gbé
inu agọ́:
43 Ki iran-iran nyin ki o le mọ̀ pe, Emi
li o mu awọn ọmọ Israeli gbé inu agọ́, ni-
gbati mo mú wọn lati ilẹ Egipti jade wá:
Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.
44 Mose si sọ gbogbo ajọ OLUWA wọnyi
fun awọn ọmọ Israeli.

## ORI 24.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Fi aṣẹ fun awọn ọmọ Israeli pe, ki
nwọn ki o mú oróro daradara ti olifi gigún
fun ọ wá, fun imọlẹ lati ma mu fitila jó
nigbagbogbo.
3 Lẹhin ode aṣọ-ikele ẹrí, ninu agọ́ ajọ,
ni ki Aaroni ki o tọju rẹ̀ lati aṣalẹ di owurọ̀,
nigbagbogbo niwaju OLUWA: ìlana ni titi-
lai ni iran-iran nyin.
4 Ki o si tọju fitila lori ọpá-fitila mimọ́
nì nigbagbogbo niwaju OLUWA.
5 Ki iwọ ki o si mú iyẹfun daradara, ki
o si yan ìṣu-àkara mejila ninu rẹ̀: idamẹwa
meji òṣuwọn ni ki o wà ninu ìṣu-àkara kan.
6 Ki iwọ ki o si tò wọn li ẹsẹ meji, mẹfa
li ẹsẹ kan, lori tabili mimọ́ niwaju OLUWA.
7 Ki iwọ ki o si fi turari daradara sori
ẹsẹ kọkan, ki o le wà lori ìṣu-àkara na fun
iranti, ani ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA.
8 Li ọjọjọ́ isimi ni ki ẹ ma tun u tò ni-
waju OLUWA titi; gbigbà ni lọwọ awọn
ọmọ Israeli nipa majẹmu titi aiye.
9 Ki o si ma jẹ́ ti Aaroni ati ti awọn ọmọ
rẹ̀; ki nwọn ki o si ma jẹ ẹ ni ibi mimọ́
kan: nitoripe mimọ́ julọ ni fun u ninu ẹbọ
OLUWA ti a fi iná ṣe, ìlana titilai.
10 Ati ọmọkọnrin obirin Israeli kan, ti
baba rẹ̀ ṣe ara Egipti, o jade lọ ninu awọn
ọmọ Israeli: ọmọkọnrin obirin Israeli yi
ati ọkọnrin Israeli kan si jà ni ibudó.
11 Eyi ọmọkọnrin obirin Israeli yi, sọ̀rọ
buburu si Orukọ nì, o si fi bú: nwọn si mú
u tọ̀ Mose wá. Orukọ iya rẹ̀ ama jẹ Ṣelo-
miti, ọmọbirin Dibri, ti ẹ̀ya Dani.

Digitized by Google

12 Nwọn si ha a mọ́ ile-ìde, titi a o fi fi
inu Oluwa hàn fun wọn.
13 Oluwa si sọ fun Mose pe,
14 Mú ẹniti o ṣe ifibu nì wá sẹhin ibudó;
ki gbogbo awọn ti o si gbọ́ ọ ki o fi ọwọ́
wọn lé ori rẹ̀, ki gbogbo ijọ enia ki o le sọ
ọ li okuta.
15 Ki iwọ ki o si sọ fun awọn ọmọ Israeli
pe, Ẹnikẹni ti o ba fi Ọlọrun rẹ̀ bú yio rù
ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀.
16 Ati ẹniti o sọ̀rọ-buburu si orukọ
Oluwa, pipa ni ki a pa a: gbogbo ijọ
enia ni ki o sọ ọ li okuta pa nitõtọ: ati
alejò, ati ibilẹ, nigbati o ba sọ̀rọ-buburu si
orukọ Oluwa, pipa li a o pa a.
17 Ati ẹniti o ba gbà ẹmi enia, pipa li a
o pa a:
18 Ẹniti o ba si lù ẹran kan pa, ki o san
a pada: ẹmi fun ẹmi.
19 Bi ẹnikan ba si ṣe abùkun kan si ara
ẹnikeji rẹ̀; bi o ti ṣe, bẽni ki a ṣe si i;
20 Ẹ̀ya fun ẹ̀ya, oju fun oju, ehin fun
ehin; bi on ti ṣe abùkun si ara enia, bẽni
ki a ṣe si i.
21 Ẹniti o ba si lù ẹran pa, ki o san a
pada: ẹniti o ba si lù enia pa, a o pa a.
22 Irú ofin kan li ẹnyin o ní, gẹgẹ bi
fun alejò bẽni fun ibilẹ: nitoripe Emi li
Oluwa Ọlọrun nyin.
23 Mose si sọ fun awọn ọmọ Israeli pe,
ki nwọn ki o mú ẹniti o ṣe ifibu nì jade lọ
sẹhin ibudó, ki nwọn ki o si sọ ọ li okuta
pa. Awọn ọmọ Israeli si ṣe bi Oluwa ti fi
aṣẹ fun Mose.

## ORI 25.

OLUWA si sọ fun Mose li òke Sinai pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba dé ilẹ ti mo
fi fun nyin, nigbana ni ki ilẹ na ki o pa
isimi kan mọ́ fun Oluwa.
3 Ọdún mẹfa ni iwọ o fi gbìn oko rẹ,
ọdún mẹfa ni iwọ o si fi rẹwọ ọgbà-ajara rẹ,
ti iwọ o si kó eso rẹ̀ jọ;
4 Ṣugbọn ọdún keje ki o si jasi ìgba isi-
mi fun ilẹ na, isimi fun Oluwa: iwọ kò
gbọdọ gbìn oko rẹ, bẽni iwọ kò gbọdọ rẹwọ
ọgbà-àjara rẹ.
5 Eyiti o ba lalẹ-hù ninu ikore rẹ iwọ kò
gbọdọ ká, bẽni iwọ kò gbọdọ ká eso àjara
rẹ ti iwọ kò rẹ́-lọwọ: nitoripe ọdún isimi
ni fun ilẹ na.
6 Ọdún isimi ilẹ na yio si ma ṣe ohunjijẹ
fun nyin; fun iwọ, ati fun iranṣẹ rẹ ọkọn-
rin, ati fun iranṣẹ rẹ obirin, ati fun ala-
gbaṣe rẹ, ati fun alejò rẹ ti nṣe atipo lọdọ rẹ;
7 Ati fun ohunọ̀sin rẹ, ati fun ẹran ti
mbẹ ni ilẹ rẹ, ni ki ibisi rẹ̀ gbogbo ki o ṣe
onjẹ fun.
8 Ki iwọ ki o si kà ọdún isimi meje fun
ara rẹ, ọdún meje ìgba meje; ati akokò
ọdún isimi meje ni yio jẹ́ ọdún mọkandilã-
dọta fun ọ.
9 Ki iwọ ki o si mu ki ipè ki o dún ni
ijọ́ kẹwa oṣù keje, li ọjọ́ ètutu ni ki ẹnyin
ki o mu ipè na dún ni gbogbo ilẹ nyin.
10 Ki ẹnyin ki o si yà arãdọta ọdún
simimọ́, ki ẹnyin ki o si kede idasilẹ ni ilẹ
na fun gbogbo awọn ti ngbé inu rẹ̀: yio si
ma jẹ́ jubeli fun nyin; ki ẹnyin ki o si
pada olukuluku si ilẹ-iní rẹ̀, ki olukuluku
nyin ki o si pada sinu idile rẹ̀.
11 Ọdún jubeli ni ki arãdọta ọdún ki o
jasi fun nyin: ẹnyin kò gbọdọ gbìn, bẽli
ẹnyin kò gbọdọ ká ilalẹ-hù inu rẹ̀, bẽli
ẹnyin kò gbọdọ ká eso àjara rẹ̀ ti a kò rẹ-
lọwọ.
12 Nitoripe jubeli ni; mimọ́ ni ki o jasi
fun nyin: ibisi rẹ̀ ni ki ẹnyin o ma jẹ lati
inu oko wa.
13 Li ọdún jubeli yi ni ki olukuluku
nyin ki o pada lọ si ilẹ-iní rẹ̀.
14 Bi iwọ ba si tà ọjà fun ẹnikeji rẹ,
tabi bi iwọ ba rà lọwọ ẹnikeji rẹ, ẹnyin kò
gbọdọ rẹ ara nyin jẹ:
15 Gẹgẹ bi iye ọdún lẹhin jubeli ni ki
iwọ ki o rà lọwọ ẹnikeji rẹ, ati gẹgẹ bi iye
ọdún ikore rẹ̀ ni ki o tà fun ọ.
16 Gẹgẹ bi ọ̀pọ ọdún ni ki iwọ ki o bù
owo rẹ̀ sí i, ati gẹgẹ bi ọdún rẹ̀ ti fàsẹhin,
ni ki iwọ ki o si bù owo rẹ̀ kù; nitoripe
gẹgẹ bi iye ọdùn ikore ni ki o tà fun ọ.
17 Nitorina ẹnyin kò gbọdọ rẹ ara nyin
jẹ; bikoṣe pe ki iwọ ki o bẹ̀ru Ọlọrun rẹ:
nitoripe Emi li Oluwa Ọlọrun nyin.
18 Nitorina ki ẹnyin ki o ma ṣe ìlana
mi, ki ẹ si ma pa ofin mi mọ́, ki ẹ si ma ṣe
wọn; ẹnyin o si ma gbé ilẹ na li ailewu.
19 Ilẹ na yio si ma mú ibisi rẹ̀ wá, ẹli
si ma jẹ ajẹyo, ẹ o si ma gbé inu rẹ̀ o
ailewu.
20 Bi ẹnyin ba si wipe, Kili awa o ha
ma jẹ li ọdún keje? sa wo o, awa kò gbọdọ
gbìn, bẽli awa kò gbọdọ kó ire wa:
21 Nigbana li emi o fi aṣẹ ibukún mi
fun nyin li ọdún kẹfa, on o si so eso jade
fun nyin fun ọdún mẹta.
22 Ẹnyin o si gbìn li ọdún kẹjọ, ẹnyin
o si ma jẹ ninu eso lailai titi di ọdún kẹsan,
titi eso rẹ̀ yio fi dé ni ẹnyin o ma jẹ ohun
isigbẹ.
23 Ẹnyin kò gbọdọ tà ilẹ lailai; nito-

Digitized by Google

ripe ti emi ni ilẹ: nitoripe alejò ati atipo
ni nyin lọdọ mi.
24 Ati ni gbogbo ilẹ-iní nyin ki ẹnyin ki
o si ma ṣe ìrapada fun ilẹ.
25 Bi arakọnrin rẹ ba di talakà, ti o ba
si tà ninu ilẹ-iní rẹ̀, bi ẹnikan ninu awọn
ibatan rẹ̀ ba si wá lati rà a, njẹ ki o rà eyiti
arakọnrin rẹ̀ ti tà pada.
26 Bi ọkọnrin na kò ba ní ẹnikan ti yio
rà a pada, ti on tikara rẹ̀ ti di olowo ti o
ní to lati rà a pada;
27 Nigbana ni ki o kà ọdún ìta rẹ̀, ki o
si mú elé owo rẹ̀ pada fun ẹniti o tà a fun,
ki on ki o le pada lọ si ilẹ-iní rẹ̀.
28 Ṣugbọn bi o ba ṣepe on kò le san a
pada fun u, njẹ ki ohun ti o tà na ki o gbé
ọwọ́ ẹniti o rà a titi di ọdún jubeli: yio si
bọ́ ni jubeli, on o si pada lọ si ilẹ-iní rẹ̀.
29 Bi ọkọnrin kan ba si tà ile gbigbé
kan ni ilu olodi, njẹ ki o rà a pada ni ìwọn
ọdún kan lẹhin ti o tà a; ni ìwọn ọdún kan
ni ki o rà a pada.
30 Bi a kò ba si rà a ni ìwọn ọdún kan
gbako, njẹ ki ile na ki o di ti ẹniti o rà a
titilai ni iran-iran rẹ̀: ki yio bọ́ ni jubeli.
31 Ṣugbọn ile ileto wọnni ti kò ni odi
yi wọn ká awọn li a kà si ibi oko ilu: ìra-
pada li awọn wọnni, nwọn o si bọ́ ni jubeli.
32 Ṣugbọn niti ilu awọn ọmọ Lefi, ile ilu
iní wọn, ni awọn ọmọ Lefi o ma ràpada
nigbakugba.
33 Bi ẹnikan ba si rà lọwọ awọn ọmọ
Lefi, njẹ ile ti a tà na, ni ilu iní rẹ̀, ki o
bọ́ ni jubeli: nitoripe ile ilu awọn ọmọ
Lefi ni ilẹ-iní wọn lãrin awọn ọmọ Israeli.
34 Ṣugbọn ilẹ ẹba ilu wọn ni nwọn kò
gbọdọ tà; nitoripe ilẹ-iní wọn ni titi aiye.
35 Ati bi arakọnrin rẹ ba di talakà, ti
ọwọ́ rẹ̀ ba si rẹlẹ lọdọ rẹ; njẹ ki iwọ ki o
ràn a lọwọ; ibaṣe alejò, tabi atipo; ki on
ki o le wà pẹlu rẹ.
36 Iwọ máṣe gbà elé lọwọ rẹ̀, tabi ẹdá;
ṣugbọn bẹ̀ru Ọlọrun rẹ; ki arakọnrin rẹ ki
o le wà pẹlu rẹ.
37 Iwọ kò gbọdọ fi owo rẹ fun u li ẹdá,
tabi ki o wín i li onjẹ rẹ fun asanlé.
38 Emi li OLUWA Ọlọrun nyin, ti o mú
nyin lati ilẹ Egipti jade wá, lati fi ilẹ
Kenaani fun nyin, ati lati ma ṣe Ọlọrun
nyin.
39 Ati bi arakọnrin rẹ ti mba ọ gbé ba
di talakà, ti o si tà ara rẹ̀ fun ọ; iwọ kò
gbọdọ sìn i ni ìsin-ẹrú:
40 Bikoṣe bi alagbaṣe, ati bi atipo, ni ki
o ma ba ọ gbé, ki o si ma sìn ọ titi di
ọdún jubeli:
41 Nigbana ni ki o lọ kuro lọdọ rẹ, ati
on ati awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀, ki o si pada lọ
si idile rẹ̀, ati si ilẹ-iní awọn baba rẹ̀ ni ki
o pada si.
42 Nitoripe iranṣẹ mi ni nwọn iṣe, ti mo
mú lati ilẹ Egipti jade wá: a kò gbọdọ tà
wọn bi ẹni tà ẹrú.
43 Iwọ kò gbọdọ fi irorò sìn i; ṣugbọn
ki iwọ ki o bẹ̀ru Ọlọrun rẹ.
44 Ati awọn ẹrú rẹ ọkọnrin, ati awọn
ẹrú rẹ obirin, ti iwọ o ní; ki nwọn ki o jẹ́
ati inu awọn orilẹ-ède wá ti o yi nyin ká,
ninu wọn ni ki ẹnyin ki o ma rà awọn ẹrú-
ọkọnrin ati awọn ẹrú-obirin.
45 Pẹlupẹlu ninu awọn ọmọ alejò ti nṣe
atipo pẹlu nyin, ninu wọn ni ki ẹnyin ki o
rà, ati ninu awọn idile wọn ti mbẹ pẹlu
nyin, ti nwọn bi ni ilẹ nyin: nwọn o si jẹ
iní nyin.
46 Ẹnyin o si ma fi wọn jẹ ogún fun
awọn ọmọ nyin lẹhin nyin, lati ní wọn ni
iní; ẹnyin o si ma sìn wọn lailai: ṣugbọn
ninu awọn arakọnrin nyin awọn ọmọ Israeli,
ẹnikan kò gbọdọ fi irorò sìn ẹnikeji rẹ̀.
47 Ati bi alejò tabi atipo kan ba di ọlọrọ̀
lọdọ rẹ, ati arakọnrin rẹ kan leti ọdọ rẹ̀
ba di talakà, ti o ba si tà ara rẹ̀ fun alejò
tabi atipo na leti ọdọ rẹ, tabi fun ibatan
idile alejò na:
48 Lẹhin igbati o tà ara rẹ̀ tán, a si tún
le rà a pada; ọkan ninu awọn arakọnrin
rẹ̀ le rà a:
49 Ibaṣe arakọnrin õbi rẹ̀, tabi ọmọ ara-
kọnrin õbi rẹ̀, le rà a, tabi ibatan rẹ̀ ninu
idile rẹ̀ le rà a; tabi bi o ba di ọlọrọ̀, o le
rà ara rẹ̀.
50 Ki o si ba ẹniti o rà a ṣiro lati ọdún
ti o ti tà ara rẹ̀ fun u titi di ọdún jubeli:
ki iye owo ìta rẹ̀ ki o si ri gẹgẹ bi iye ọdún,
gẹgẹ bi ìgba alagbaṣe ni ki o ri fun u.
51 Bi ọdún rẹ̀ ba kù pupọ̀ sibẹ̀, gẹgẹ bi
iye wọn ni ki o si san owo ìrasilẹ rẹ̀ pada
ninu owo ti a fi rà a.
52 Bi o ba si ṣepe kìki ọdún diẹ li o kù
titi di ọdún jubeli, njẹ ki o ba a ṣiro, gẹgẹ
bi iye ọdún rẹ̀ ni ki o san owo ìrasilẹ rẹ̀
pada.
53 Bi alagbaṣe ọdọdún ni ki o ma ba a
gbé: ki on ki o máṣe fi irorò sìn i li oju rẹ.
54 Bi a kò ba si fi wọnyi rà a silẹ, njẹ
ki o jade lọ li ọdún jubeli, ati on, ati awọn
ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀.
55 Nitoripe iranṣẹ mi li awọn ọmọ Isra-
eli iṣe; iranṣẹ mi ni nwọn ti mo mú lati
ilẹ Egipti jade wá: Emi li OLUWA Ọlọrun
nyin.

Digitized by Google

## ORI 26.

ENYIN kò gbọdọ yá oriṣa, bẽni ẹnyin kò gbọdọ gbé ere tabi ọwọ̀n kan dide naró fun ara nyin, bẽli ẹnyin kò gbọdọ gbé ere okuta gbigbẹ kalẹ ni ilẹ nyin, lati tẹriba fun u: nitoripe Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.

2 Ki ẹnyin ki o pa ọjọ́-isimi mi mọ́, ki ẹ si bọ̀wọ fun ibi mimọ́ mi: Emi li OLUWA.

3 Bi ẹnyin ba nrìn ninu ìlana mi, ti ẹ si npa ofin mi mọ́, ti ẹ si nṣe wọn;

4 Nigbana li emi o fun nyin li òjo li akokò rẹ̀, ilẹ yio si ma mú ibisi rẹ̀ wá, igi oko yio si ma so eso wọn.

5 Ipakà nyin yio si dé ìgba ikore àjara, ìgba ikore àjara yio si dé ìgba ifunrugbìn: ẹnyin o si ma jẹ onjẹ nyin li ajẹyo, ẹ o si ma gbé ilẹ nyin li ailewu.

6 Emi o si fi alafia si ilẹ na, ẹnyin o si dubulẹ, kò si sí ẹniti yio dẹruba nyin: emi o si mu ki ẹranko buburu ki o dasẹ kuro ni ilẹ na, bẽni idà ki yio là ilẹ nyin já.

7 Ẹnyin o si lé awọn ọtá nyin, nwọn o si ti ipa idà ṣubu niwaju nyin.

8 Marun ninu nyin yio si lé ọgọrun, ọgọrun ninu nyin yio si lé ẹgbarun: awọn ọtá nyin yio si ti ipa idà ṣubu niwaju nyin.

9 Nitoriti emi o fi ojurere wò nyin, emi o si mu nyin bisi i, emi o si sọ nyin di pupọ̀, emi o si gbé majẹmu mi kalẹ pẹlu nyin.

10 Ẹnyin o si ma jẹ ohun isigbẹ, enyin o si ma kó ohun ẹgbẹ jade nitori ohun titun.

11 Emi o si gbé ibugbé mi kalẹ lãrin nyin: ọkàn mi ki yio si korira nyin.

12 Emi o si ma rìn lãrin nyin, emi o si ma ṣe Ọlọrun nyin, ẹnyin o si ma ṣe enia mi.

13 Emi li OLUWA Ọlọrun nyin ti o mú nyin lati ilẹ Egipti jade wá, ki ẹnyin ki o máṣe wà li ẹrú wọn; emi si ti dá ìde àjaga nyin, mo si mu nyin rìn lõrogangan.

14 Ṣugbọn bi ẹnyin kò ba gbọ́ ti emi, ti ẹ kò si ṣe gbogbo ofin wọnyi;

15 Bi ẹnyin ba si gàn ìlana mi, tabi bi ọkàn nyin ba korira idajọ mi, tobẽ ti ẹnyin ki yio fi ṣe gbogbo ofin mi, ṣugbọn ti ẹnyin dà majẹmu mi;

16 Emi pẹlu yio si ṣe eyi si nyin; emi o tilẹ rán ẹ̀ru si nyin, àrun-igbẹ ati òjojo gbigbona, ti yio ma jẹ oju run, ti yio si ma mú ibinujẹ ọkàn wá: ẹnyin o si fun irugbín nyin lasan, nitoripe awọn ọtá nyin ni yio jẹ ẹ.

17 Emi o si kọ oju mi si nyin, a o si pa nyin niwaju awọn ọtá nyin: awọn ti o kerira nyin ni yio si ma ṣe olori nyin; ẹnyin o si ma sá nigbati ẹnikan kò lé nyin.

18 Ninu gbogbo eyi, bi ẹnyin kò ba si gbọ́ ti emi, nigbana li emi o jẹ nyin ni ìya ni ìgba meje si i nitori ẹ̀ṣẹ nyin.

19 Emi o si ṣẹ́ igberaga agbara nyin; emi o si sọ ọrun nyin dabi irin, ati ilẹ nyin dabi idẹ:

20 Ẹnyin o si lò agbara nyin lasan: nitoriti ilẹ nyin ki yio mú ibisi rẹ̀ wá, bẽni igi ilẹ nyin ki yio so eso wọn.

21 Bi ẹnyin ba si nrìn lodi si mi, ti ẹnyin kò si gbọ́ ti emi; emi o si mú iyọnu ìgba meje wá si i lori nyin gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ nyin.

22 Emi o si rán ẹranko wá sinu nyin pẹlu, ti yio ma gbà nyin li ọmọ, ti yio si ma run nyin li ẹran-ọ̀sin, ti yio si mu nyin dinkù; opópo nyin yio si dahoro.

23 Bi ẹnyin kò ba gbà ìkilọ mi nipa nkan wọnyi, ṣugbọn ti ẹnyin o ma rìn lodi si mi;

24 Nigbana li emi pẹlu yio ma rìn lodi si nyin, emi o si jẹ nyin ni ìya si i ni ìgba meje nitori ẹ̀ṣẹ nyin.

25 Emi o si mú idà wá sori nyin, ti yio gbà ẹsan majẹmu mi; a o si kó nyin jọ pọ̀ ninu ilu nyin, emi o rán ajakalẹ-àrun sãrin nyin; a o si fi nyin lé ọtá lọwọ.

26 Nigbati mo ba ṣẹ́ ọpá onjẹ nyin, obirin mẹwa yio yan àkara nyin ninu àro kan, ìwọn ni nwọn o si ma fi fun nyin li àkara nyin: ẹnyin o si ma jẹ, ẹ ki yio si yó.

27 Ninu gbogbo eyi bi ẹnyin kò ba si gbọ́ ti emi, ti ẹ ba si nrìn lodi si mi;

28 Nigbana li emi o ma rìn lodi si nyin pẹlu ni ikannu; emi pẹlu yio si nà nyin ni ìgba meje nitori ẹ̀ṣẹ nyin.

29 Ẹnyin o si jẹ ẹran-ara awọn ọmọ nyin ọkọnrin, ati ẹran-ara awọn ọmọ nyin obirin li ẹnyin o jẹ.

30 Emi o si run ibi giga nyin wọnni, emi o si ke ere nyin lulẹ, emi o si wọ́ okú nyin sori okú oriṣa nyin; ọkàn mi yio si korira nyin.

31 Emi o si sọ ilu nyin di ahoro, emi o si sọ ibi mimọ́ nyin di ahoro, emi ki yio gbọ́ adùn õrùn didùn nyin mọ́.

32 Emi o si sọ ilẹ na di ahoro: ẹnu yio si yà awọn ọtá nyin ti ngbé inu rẹ̀ si i.

33 Emi o si tú nyin ká sinu awọn orilẹ-èdè, emi o si yọ idà tì nyin lẹhin: ilẹ nyin yio si di ahoro, ati ilu nyin yio di ahoro.

34 Nigbana ni ilẹ na yio ní isimi rẹ̀, ni gbogbo ọjọ́ idahoro rẹ̀, ẹnyin o si wà ni ilẹ

Digitized by Google

awọn ọtá nyin; nigbana ni ilẹ yio simi, ti
yio si ní isimi rẹ̀.
35 Ni gbogbo ọjọ́ idahoro rẹ̀ ni yio ma
simi; nitoripe on kò simi li ọjọ́-isimi nyin,
nigbati ẹnyin ngbé inu rẹ̀.
36 Ati lara awọn ti o kù lãye ninu nyin,
li emi o rán ijàiya si ọkàn wọn ni ilẹ awọn
ọtá wọn: iró mìmì ewé yio si ma lé wọn;
nwọn o si sá, bi ẹni sá fun idà; nwọn o si
ma ṣubu nigbati ẹnikan kò lepa.
37 Nwọn o si ma ṣubulù ara wọn, bi
enipe niwaju idà, nigbati kò sí ẹniti nlepa:
ẹnyin ki yio si lí agbara lati duro niwaju
awọn ọtá nyin.
38 Ẹnyin o si ṣegbé ninu awọn orilẹ-ède,
ilẹ awọn ọtá nyin yio si mú nyin jẹ.
39 Ati awọn ti o kù ninu nyin yio si
joro ninu ẹ̀ṣẹ wọn ni ilẹ awọn ọtá nyin; ati
nitori ẹ̀ṣẹ awọn baba wọn pẹlu ni nwọn o
ma joro pẹlu wọn.
40 Bi nwọn ba si jẹwọ irekọja wọn, ati
irekọja awọn baba wọn, pẹlu ọ̀tẹ wọn ti
nwọn ti ṣe si mi, ati pẹlu nitoripe nwọn ti
rìn lodi si mi:
41 Emi pẹlu rìn lodi si wọn, mo si mú
wọn wá si ilẹ awọn ọtá wọn: njẹ bi àiya
wọn alaikọlà ba rẹ̀silẹ, ti nwọn ba si gbà
ibawi ẹ̀ṣẹ wọn;
42 Nigbana li emi o ranti majẹmu mi
pẹlu Jakobu; ati majẹmu mi pẹlu Isaaki,
ati majẹmu mi pẹlu Abrahamu li emi o
ranti; emi o si ranti ilẹ na.
43 Nwọn o si fi ilẹ na silẹ, on o si ní
isimi rẹ̀, nigbati o ba di ahoro li aisí wọn;
nwọn o si gbà ibawi ẹ̀ṣẹ wọn: nitoripe, ani
nitoripe nwọn gàn idajọ mi, ati ọkàn wọn
korira ìlana mi.
44 Ṣugbọn sibẹ̀ ninu gbogbo eyina, ni-
gbati nwọn ba wà ni ilẹ awọn ọtá wọn, emi
ki yio tà wọn nù, bẽli emi ki yio korira
wọn, lati run wọn patapata, ati lati dà
majẹmu mi pẹlu wọn: nitoripe Emi li
OLUWA Ọlọrun wọn:
45 Ṣugbọn nitori wọn emi o ranti majẹ-
mu awọn baba nla wọn, ti mo mú lati ilẹ
Egipti jade wá li oju awọn orilẹ-ède, ki emi
ki o le ma ṣe Ọlọrun wọn: Emí li OLUWA.
46 Wọnyi ni ìlana ati idajọ, ati ofin ti
OLUWA dásilẹ, lãrin on ati awọn ọmọ Isra-
eli li òke Sinai nipa ọwọ́ Mose.

## ORI 27.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Nigbati enia kan ba jẹ́ ẹjẹ́ pa-
taki kan, ki awọn enia na ki o jẹ́ ti OLUWA
gẹgẹ bi idiyelé rẹ.
3 Idiyelé rẹ fun ọkọnrin yio si jẹ́ lati ẹni
ogún ọdún lọ titi di ọgọta ọdún, idiyelé rẹ
yio si jẹ́ ãdọta ṣekeli fadakà, gẹgẹ bi ṣekeli
ibi mimọ́.
4 Bi on ba si ṣe obirin, njẹ ki idiyelè rẹ
ki o jẹ́ ọgbọn ṣekeli.
5 Bi o ba si ṣepe lati ọmọ ọdún marun
lọ, titi di ẹni ogún ọdún, njẹ ki idiyelé rẹ
ki o jẹ́ ogún ṣekeli fun ọkọnrin, ati fun
obirin ṣekeli mẹwa.
6 Bi o ba si ṣepe lati ọmọ oṣù kan lọ titi
di ọmọ ọdún marun, njẹ ki idiyelé rẹ fun
ọkọnrin ki o jẹ́ ṣekeli fadakà marun, ati
fun obirin, idiyelé rẹ yio jẹ́ ṣekeli fadakà
mẹta.
7 Bi o ba si ṣe lati ẹni ọgọta ọdún lọ ta-
bi jù bẽ lọ; bi o ba jẹ́ ọkọnrin, njẹ ki idi-
yelé rẹ ki o jẹ́ ṣekeli mẹdogun, ati fun
obirin ṣekeli mẹwa.
8 Ṣugbọn bi on ba ṣe talakà jù idiyelé rẹ
lọ, njẹ ki o lọ siwaju alufa, ki alufa ki o
diyelé e; gẹgẹ bi agbara ẹniti o jẹ́ ẹjẹ́ na ni
ki alufa ki o diyelé e.
9 Bi o ba si ṣepe ẹran ni, ninu eyiti enia
mú ọrẹ-ẹbọ tọ̀ OLUWA wá, gbogbo eyiti
ẹnikẹni ba múwa ninu irú nkan wọnni fun
OLUWA ki o jẹ́ mimọ́.
10 On kò gbọdọ pa a dà, bẽni kò gbọdọ
pàrọ rẹ̀, rere fun buburu, tabi buburu fun
rere: bi o ba ṣepe yio pàrọ rẹ̀ rára, ẹran fun
ẹran, njẹ on ati ipàrọ rẹ̀ yio si jẹ́ mimọ́.
11 Bi o ba si ṣepe ẹran alaimọ́ kan ni,
ninu eyiti nwọn kò mú rubọ si OLUWA, njẹ
ki o mú ẹran na wá siwaju alufa:
12 Ki alufa ki o si diyelé e, ibaṣe rere
tabi buburu: bi iwọ alufa ba ti diyelé e,
bẽni ki o ri.
13 Ṣugbọn bi o ba fẹ́ rà a pada rara, njẹ
ki o fi idamarun rẹ̀ kún idiyelé rẹ.
14 Bi enia kan yio ba si yà ile rẹ̀ sọ̀tọ
lati jẹ́ mimọ́ fun OLUWA, njẹ ki alufa ki o
diyelé e, ibaṣe rere tabi buburu: bi alufa
ba ti diyelé e, bẽni ki o ri.
15 Ati bi ẹniti o yà a sọ̀tọ ba nfẹ́ rà ile
rẹ̀ pada, njẹ ki o fi idamarun owo idiyelé
rẹ̀ kún u, yio si jẹ́ tirẹ̀.
16 Bi enia kan ba si nfẹ́ yà ninu oko ti
o jogún sọ̀tọ fun OLUWA, njẹ ki idiyelé rẹ
ki o jẹ́ bi irugbìn rẹ̀; òṣuwọn homeri iru-
gbìn barle kan ãdọta ṣekeli fadakà.
17 Bi o ba yà oko rẹ̀ sọ̀tọ lati ọdún ju-
beli wá, gẹgẹ bi idiyelé rẹ bẽni ki o ri.
18 Ṣugbọn bi o ba yà oko rẹ̀ sọ̀tọ lẹhin
ọdún jubeli, njẹ ki alufa ki o ṣiro owo rẹ̀

Digitized by Google

fun u, gẹgẹ bi ìwọn ọdún ti o kù, titi di ọdún jubeli, a o si din i kù ninu idiyelé rẹ.

19 Ati bi ẹniti o yà oko na sọ̀tọ ba fẹ́ rà a pada, njẹ ki o fi idamarun owo idiyelé rẹ kún u, yio si jẹ́ tirẹ̀.

20 Bi on kò ba si fẹ́ rà oko na pada, tabi bi o ba ti tà oko na fun ẹlomiran, ki a máṣe rà a pada mọ́.

21 Ṣugbọn oko na, nigbati o ba yọ li ọdún jubeli, ki o jẹ́ mimọ́ fun OLUWA, bi oko ìya-sọtọ ; iní rẹ̀ yio jẹ́ ti alufa.

22 Ati bi ẹnikan ba yà oko kan sọ̀tọ fun OLUWA ti on ti rà, ti ki iṣe ninu oko ti o jogún ;

23 Njẹ ki alufa ki o ṣiro iye idiyelé rẹ̀ fun u, titi di ọdún jubeli : ki on ki o si fi idiyelé rẹ li ọjọ́ na, bi ohun mimọ́ fun OLUWA.

24 Li ọdún jubeli ni ki oko na ki o pada sọdọ ẹniti o rà a, ani sọdọ rẹ̀ ti ẹniti ini ilẹ na iṣe.

25 Ki gbogbo idiyelé rẹ ki o si jẹ́ gẹgẹ bi ṣekeli ibi mimọ́ : ogún gera ni ṣekeli kan.

26 Kìki akọ́bi ẹran, ti iṣe akọ́bi ti OLUWA, li ẹnikan kò gbọdọ yàsọtọ ; ibaṣe akọmalu, tabi agutan : ti OLUWA ni.

27 Bi o ba ṣe ti ẹran alaimọ́ ni, njẹ ki o gbà a silẹ gẹgẹ bi idiyelé rẹ, ki o si fi idamarun rẹ̀ kún u : tabi bi kò ba si rà a pada, njẹ ki a tà a, gẹgẹ bi idiyelé rẹ.

28 Ṣugbọn kò sí ohun ìyasọtọ kan, ti enia ba yàsọtọ fun OLUWA ninu ohun gbogbo ti o ní, ati enia, ati ẹran, ati ilẹ-iní rẹ̀, ti a gbọdọ tà tabi ti a gbọdọ rà pada : ohun gbogbo ti a ba yàsọtọ mimọ́ julọ ni si OLUWA.

29 Kò sí ẹni ìyasọtọ ti a ba yàsọtọ ninu enia, ti a le gbàsilẹ ; pipa ni ki a pa a.

30 Ati gbogbo idamẹwa ilẹ na ibaṣe ti irugbìn ilẹ na, tabi ti eso igi, ti OLUWA ni: mimọ́ ni fun OLUWA.

31 Bi o ba ṣepe enia ba ràpada rára ninu ohun idamẹwa rẹ̀, ki o si fi idamarun kún u.

32 Ati gbogbo idamẹwa ọwọ́ ẹran, tabi ti agbo-ẹran, ani ohunkohun ti o ba kọja labẹ ọpá, ki ẹkẹwa ki o jẹ́ mimọ́ fun OLUWA.

33 Ki o máṣe yẹ̀ ẹ wò bi o jẹ́ rere tabi buburu, bẹ̃li on kò gbọdọ pàrọ rẹ̀ : bi o ba si ṣepe o pàrọ rẹ̀ rara, njẹ ati on ati ipàrọ rẹ̀ yio jẹ́ mimọ́ ; a kò gbọdọ rà a pada.

34 Wọnyi li ofin, ti OLUWA palaṣẹ fun Mose fun awọn ọmọ Israeli li òke Sinai.

---

## IWE KẸRIN TI MOSE,

### TI A NPE NI

# NUMERI.

### ORI 1.

OLUWA si sọ fun Mose ni ijù Sinai, ninu agọ́ ajọ, li ọjọ́ kini oṣù keji, li ọdún keji, ti nwọn jade lati ilẹ Egipti wá, wipe,

2 Ẹ kaye gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli, nipa idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi iye orukọ, olukuluku ọkọnrin, nipa ori wọn ;

3 Lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ, gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun ni Israeli, iwọ ati Aaroni ni ki o kaye wọn gẹgẹ bi ogun wọn.

4 Ki ọkọnrin kọkan lati inu olukuluku ẹ̀ya ki o si wà pẹlu nyin ; ki olukuluku jẹ olori ile awọn baba rẹ̀.

5 Wọnyi si li orukọ awọn ọkọnrin na ti yio duro pẹlu nyin : ti Reubeni ; Elisuri ọmọ Ṣedeuri.

6 Ti Simeoni ; Ṣelumieli ọmọ Suriṣaddai.

7 Ti Juda ; Naṣoni ọmọ Amminadabu.

8 Ti Issakari ; Netaneli ọmọ Suari.

9 Ti Sebuluni ; Eliabu ọmọ Heloni.

10 Ti awọn ọmọ Josefu : ti Efraimu ; Elliṣama ọmọ Ammihudu : ti Manasse ; Gamalieli ọmọ Pedasuru.

11 Ti Benjamini ; Abidani ọmọ Gideoni

Digitized by Google

12 Ti Dani; Ahieseri ọmọ Ammiṣaddai.
13 Ti Aṣeri; Pagieli ọmọ Okanri.
14 Ti Gadi; Eliasafu ọmọ Deueli.
15 Ti Naftali; Ahira ọmọ Enani.
16 Wọnyi li awọn ti a yàn ninu ijọ,
olori ẹ̀ya awọn baba wọn, awọn olori ẹ-
gbegbẹrun ni Israeli.
17 Ati Mose ati Aaroni mú awọn ọkọn-
rin wọnyi ti a pè li orukọ:
18 Nwọn si pè gbogbo ijọ enia pọ̀ li ọjọ́
kini oṣù keji, nwọn si pitan iran wọn
gẹgẹ bi idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ
bi iye orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù
bẹ̃ lọ, nipa ori wọn.
19 Bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose, bẹ̃li o si
kaye wọn ni ijù Sinai.
20 Ati awọn ọmọ Reubeni, akọ́bi Israeli,
iran wọn, nipa idile wọn, nipa ile baba wọn,
gẹgẹ bi iye orukọ, nipa ori wọn, gbogbo
ọkọnrin lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ,
gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
21 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Reubeni, o jẹ́ ẹgba mẹtalelogun o le ẹdẹ-
gbẹta.
22 Ti awọn ọmọ Simeoni, iran wọn, nipa
idile wọn, nipa ile baba wọn, awọn ti a kà
ninu wọn, gẹgẹ bi iye orukọ, nipa ori wọn,
gbogbo ọkọnrin lati ẹni ogún ọdún lọ ati
jù bẹ̃ lọ, gbogbo awọn ti o le jade lọ si
ogun;
23 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Simeoni, o jẹ́ ẹgba mọkandilọgbọ̀n o le
ẹdegbeje.
24 Ti awọn ọmọ Gadi, iran wọn, nipa
idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi iye
orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ,
gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
25 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Gadi, o jẹ́ ẹgba mejilelogun o le ẹ̃dọta-
lelẹgbẹjọ.
26 Ti awọn ọmọ Juda, iran wọn, nipa
idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi iye
orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ,
gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
27 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Juda, o jẹ́ ẹgba mẹtadilogoji o le ẹgbẹta.
28 Ti awọn ọmọ Issakari, iran wọn, nipa
idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi iye
orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ,
gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
29 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Issakari, o jẹ́ ẹgba mẹtadilọgbọ̀n o le irinwo.
30 Ti awọn ọmọ Sebuluni, iran wọn,
nipa idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi
iye orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃
lọ, gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
31 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Sebuluni, o jẹ́ ẹgba mejidilọgbọ̀n o le egbeje.
32 Ti awọn ọmọ Josefu, eyini ni, ti
awọn ọmọ Efraimu, iran wọn, nipa idile
wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi iye orukọ,
lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ, gbogbo
awọn ti o le jade lọ si ogun;
33 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Efraimu, o jẹ́ ọkẹ meji o le ẹdẹgbẹta.
34 Ti awọn ọmọ Manasse, iran wọn,
nipa idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi
iye orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃
lọ, gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
35 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Manasse, o jẹ́ ẹgba mẹrindilogun o le igba.
36 Ti awọn ọmọ Benjamini, iran wọn,
nipa idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi
iye orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ,
gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
37 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Benjamini, o jẹ́ ẹgba mẹtadilogun o le egbeje.
38 Ti awọn ọmọ Dani, iran wọn, nipa idile
wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi iye orukọ,
lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ, gbogbo
awọn ti o le jade lọ si ogun;
39 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Dani, o jẹ́ ẹgba mọkanlelọgbọ̀n o le ẹdẹ-
gbẹrin.
40 Ti awọn ọmọ Aṣeri, iran wọn, nipa
idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi iye
orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ,
gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
41 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Aṣeri, o jẹ́ ọkẹ meji o le ẹdẹgbẹjọ.
42 Ti awọn ọmọ Naftali, iran wọn, nipa
idile wọn, nipa ile baba wọn, gẹgẹ bi iye
orukọ, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jú bẹ̃ lọ,
gbogbo awọn ti o le jade lọ si ogun;
43 Awọn ti a kà ninu wọn, ninu ẹ̀ya
Naftali, o jẹ́ ẹgba mẹrindilọgbọ̀n o le egbeje.
44 Wọnyi li awọn ti a kà, ti Mose ati
Aaroni kà, ati awọn olori Israeli, ọkọnrin
mejila: olukuluku wà fun ile awọn baba rẹ̀.
45 Bẹ̃ni gbogbo awọn ti a kà ninu awọn
ọmọ Israeli, nipa ile baba wọn, lati ẹni ogún
ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ, gbogbo awọn ti o le
jade lọ si ogun ni Israeli;
46 Ani gbogbo awọn ti a kà o jẹ́ ọgbọ̀n
ọkẹ enia o le egbejidilogun din ẹ̃dọta.
47 Ṣugbọn awọn ọmọ Lefi gẹgẹ bi ẹ̀ya
baba wọn li a kò kà mọ́ wọn.
48 Nitoripe OLUWA ti sọ fun Mose pe,
49 Kìki ẹ̀ya Lefi ni ki iwọ ki o máṣe kà,
bẹ̃ni ki iwọ ki o máṣe kà iye wọn mọ́ awọn
ọmọ Israeli.
50 Ṣugbọn ki iwọ ki o yàn awọn ọmọ

Digitized by Google

Lefi sori agọ́ ẹrí, ati sori gbogbo ohun-èlo
rẹ̀, ati sori ohun gbogbo ti iṣe tirẹ̀: awọn
ni ki o ma rù agọ́, ati gbogbo ohun-èlo rẹ̀;
awọn ni yio si ma ṣe iṣẹ-ìsin rẹ̀, ki nwọn ki
o si dó yi agọ́ na ká.
51 Nigbati agọ́ na ba si ṣí siwaju, ki awọn
ọmọ Lefi ki o tú u palẹ: nigbati nwọn o ba
si pa agọ́ na, awọn ọmọ Lefi ni ki o gbé e
duro: alejò ti o ba sunmọtosi, pipa ni.
52 Ki awọn ọmọ Israeli ki o si pa agọ́
wọn, olukuluku ni ibudó rẹ̀, ati olukuluku
lẹba ọpagun rẹ̀, gẹgẹ bi ogun wọn.
53 Ṣugbọn awọn ọmọ Lefi ni ki o dó yi
agọ́ ẹrí na ká, ki ibinu ki o má ba si lara
ijọ awọn ọmọ Israeli: ki awọn ọmọ Lefi ki
o si ma ṣe itọju agọ́ ẹrí na.
54 Bayi ni awọn ọmọ Israeli si ṣe; gẹgẹ
bi gbogbo eyiti OLUWA ti paṣẹ fun Mọse,
bẹ̃ni nwọn ṣe.

## ORI 2.

OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni pe,
2 Ki olukuluku awọn ọmọ Israeli ki
o pa agọ́ rẹ̀ lẹba ọpagun rẹ̀, pẹlu asia ile
baba wọn: ki nwọn ki o pagọ́ kọjusi agọ́
ajọ yiká.
3 Ki awọn ti iṣe ti ọpagun ibudó Juda ki
o dó ni ìha gabasi si ìha ìla-õrùn, gẹgẹ bi
ogun wọn: Naṣoni ọmọ Amminadabu yio
si jẹ́ olori awọn ọmọ Juda.
4 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ẹgba mẹtadilogoji o le ẹgbẹta.
5 Ati awọn ti o pagọ́ gbè e ki o jẹ́ ẹ̀ya
Issakari: Netaneli ọmọ Suari yio si jẹ́
olori awọn ọmọ Issakari:
6 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu wọn,
jẹ́ ẹgba mẹtadilọgbọ̀n o le irinwo.
7 Ati ẹ̀ya Sebuluni: Eliabu ọmọ Heloni
yio si jẹ́ olori awọn ọmọ Sebuluni:
8 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu wọn,
jẹ́ ẹgba mejidilọgbọ̀n o le egbeje.
9 Gbogbo awọn ti a kà ni ibudó Juda jẹ́
ẹgba mẹtalelãdọrun o le irinwo, gẹgẹ bi
ogun wọn. Awọn yi ni yio kọ́ ṣí.
10 Ni ìha gusù ni ki ọpagun ibudó Reu-
beni ki o wà, gẹgẹ bi ogun wọn: Elisuru ọmọ
Ṣedeuru yio si jẹ́ olori awọn ọmọ Reubeni:
11 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ẹgba mẹtalelogun o le ẹdẹgbẹta.
12 Ati awọn ti o pagọ́ tì i ki o jẹ́ ẹ̀ya
Simeoni: Ṣelumieli ọmọ Suriṣaddai ni yio
si jẹ́ olori awọn ọmọ Simeoni:
13 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ẹgba mọkandilọgbọ̀n o le ẹdegbeje.
14 Ati ẹ̀ya Gadi: Eliasafu ọmọ Deueli ni
yio si jẹ́ olori ogun ti awọn ọmọ Gadi:
15 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ẹgba mejilelogun o le ãdọtalelẹ-
gbẹjọ.
16 Gbogbo awọn ti a kà ni ibudó Reube-
ni jẹ́ ẹgba marundilọgọrin o le ãdọtalele-
gbeje, gẹgẹ bi ogun wọn. Awọn ni yio si
ṣí ṣikeji.
17 Nigbana ni agọ́ ajọ yio si ṣí, pẹlu
ibudó, awọn ọmọ Lefi lãrin ibudó: bi nwọn
ti dó bẹ̃ni nwọn o ṣí, olukuluku ni ipò rẹ̀,
pẹlu ọpagun wọn.
18 Ni ìha ìwọ-õrùn ni ki ọpagun ibudó
Efraimu ki o wà gẹgẹ bi ogun wọn: Eliṣa-
ma ọmọ Ammihudu yio si jẹ́ olori awọn
ọmọ Efraimu:
19 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ọkẹ meji o le ẹdẹgbẹta.
20 Ati lẹba rẹ̀ ni ki ẹ̀ya Manasse ki o
wà: Gamalieli ọmọ Pedahsuru yio si jẹ́
olori awọn ọmọ Manasse:
21 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ẹgba mẹrindilogun o le igba.
22 Ati ẹ̀ya Benjamini: Abidani ọmọ
Gideoni yio si jẹ́ olori awọn ọmọ Benja-
mini:
23 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ẹgba mẹtadilogun o le egbeje.
24 Gbogbo awọn ti a kà ni ibudó Efrai-
mu, jẹ́ ẹgba mẹrinlelãdọta o le ọgọrun, gẹ-
gẹ bi ogun wọn. Awọn ni yio si ṣí ṣikẹta.
25 Ọpagun ibudó Dani ni ki o wà ni ìha
ariwa gẹgẹ bi ogun wọn: Ahie-seri ọmọ
Ammiṣaddai yio si jẹ́ olori awọn ọmọ Dani.
26 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ẹgba mọkanlelọgbọ̀n o le ẹdẹgbẹrin.
27 Ati awọn ti o dó tì i ni ki o jẹ́ ẹ̀ya
Aṣeri: Pagieli ọmọ Okrani yio si jẹ́ olori
awọn ọmọ Aṣeri:
28 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ọkẹ meji o le ẹdẹgbẹjọ.
29 Ati ẹ̀ya Naftali: Ahira ọmọ Enani
yio si jẹ́ olori awọn ọmọ Naftali:
30 Ati ogun rẹ̀, ati awọn ti a kà ninu
wọn, jẹ́ ẹgba mẹrindilọgbọ̀n o le egbeje.
31 Gbogbo awọn ti a kà ni ibudó Dani,
jẹ́ ẹgba mejidilọgọrin o le ẹgbẹjọ. Awọn
ni yio ṣí kẹhin pẹlu ọpagun wọn.
32 Eyi li awọn ti a kà ninu awọn ọmọ
Israeli gẹgẹ bi ile baba wọn: gbogbo awọn
ti a kà ni ibudó gẹgẹ bi ogun wọn, jẹ́ ọgbọ̀n
ọkẹ o le egbejidilogun din ãdọta.
33 Ṣugbọn awọn ọmọ Lefi li a kò kà mọ́
awọn ọmọ Israeli; bi OLUWA ti paṣẹ fun
Mose.
34 Awọn ọmọ Israeli si ṣe gẹgẹ bi gbogbo
eyiti OLUWA paṣẹ fun Mose: bẹ̃ni nwọn si

Digitized by Google

dó pẹlu ọpagun wọn, bẽni nwọn si nṣí, olu-
kuluku nipa idile wọn, gẹgẹ bi ile baba
wọn.

## ORI 3.

WỌNYI si li awọn iran Aaroni ati Mose
li ọjọ́ ti OLUWA bá Mose sọ̀rọ li òke
Sinai.
2 Wọnyi si li orukọ awọn ọmọ Aaroni:
Nadabu akọ́bi, ati Abihu, Eleasari, ati
Itamari.
3 Wọnyi li orukọ awọn ọmọ Aaroni,
awọn alufa ti a ta oróro si wọn li ori, ẹniti
o yàsọtọ lati ma ṣe iranṣẹ ni ipò iṣẹ alufa.
4 Nadabu ati Abihu si kú niwaju OLU-
WA, nigbati nwọn rubọ iná àjeji niwaju
OLUWA ni ijù Sinai, nwon kò si lí ọmọ:
ati Eleasari ati Itamari nṣe iṣẹ alufa niwaju
Aaroni baba wọn.
5 OLUWA si sọ fun Mose pe,
6 Mú ẹ̀ya Lefi sunmọtosi, ki o si mú
wọn wá siwaju Aaroni alufa, ki nwọn le ma
ṣe iranṣẹ fun u.
7 Ki nwọn ki o ma pa aṣẹ rẹ̀ mọ́, ati aṣẹ
gbogbo ajọ niwaju agọ́ ajọ, lati ṣe iṣẹ-ìsin
agọ́.
8 Ki nwọn ki o si ma pa gbogbo ohun-
èlo agọ́ ajọ mọ́, ati aṣẹ awọn ọmọ Israeli,
lati ṣe iṣẹ-ìsin agọ́.
9 Ki iwọ ki o si fi awọn ọmọ Lefi fun
Aaroni ati fun awọn ọmọ rẹ̀: patapata li a
fi wọn fun u ninu awọn ọmọ Israeli.
10 Ki iwọ ki o si yàn Aaroni ati awọn
ọmọ rẹ̀, ki nwọn ki o si ma duro si iṣẹ-alufa
wọn: alejò ti o ba si summọtosi pipa ni ki
a pa a.
11 OLUWA si sọ fun Mose pe,
12 Ati emi, kiyesi i, emi ti gbà awọn
ọmọ Lefi kuro lãrin awọn ọmọ Israeli ni
ipò gbogbo akọ́bi ti o ṣí inu ninu awọn ọmọ
Israeli; nitorina ti emi li awọn ọmọ Lefi
iṣe:
13 Nitoripe ti emi ni gbogbo akọ́bi:
nitoripe li ọjọ́ na ti mo kọlù gbogbo akọ́bi
ni ilẹ Egipti, ni mo yà gbogbo akọ́bi sọtọ
fun ara mi ni Israeli, ati enia ati ẹran: ti
emi ni nwọn o ma ṣe: Emi li OLUWA.
14 OLUWA si sọ fun Mose ni ijù Sinai
pe,
15 Kaye awọn ọmọ Lefi gẹgẹ bi ile baba
wọn, nipa idile wọn: gbogbo ọkọnrin lati
ẹni oṣu kan lọ ati jù bẽ lọ, ni ki iwọ ki o
kà wọn.
16 Mose si kà wọn gẹgẹ bi ọ̀rọ OLUWA,
bi a ti paṣẹ fun u.
17 Wọnyi si ni awọn ọmọ Lefi gẹgẹ
bi orukọ wọn; Gerṣoni, ati Kohati, ati
Merari.
18 Wọnyi si ni orukọ awọn ọmọ Gerṣoni
gẹgẹ bi idile wọn; Libni ati Ṣimei.
19 Ati awọn ọmọ Kohati gẹgẹ bi idile
wọn: Amramu, ati Ishari, Hebroni, ati
Usieli.
20 Ati awọn ọmọ Merari gẹgẹ bi idile
wọn; Mali, ati Muṣi. Wọnyi ni awọn
idile Lefi gẹgẹ bi ile baba wọn.
21 Ti Gerṣoni ni idile awọn ọmọ Libni,
ati idile awọn ọmọ Ṣimei; wọnyi ni idile
awọn ọmọ Gerṣoni.
22 Awọn ti a kà ninu wọn, gẹgẹ bi iye
gbogbo awọn ọkọnrin, lati ẹni oṣù kan lọ
ati jù bẽ lọ, ani iye awọn ti a kà ninu wọn,
jẹ́ ẹgbata o le ẹdẹgbẹjọ.
23 Awọn idile awọn ọmọ Gerṣoni ni ki o
dó lẹhin agọ́ ni ìha ìwọ-õrùn.
24 Ati Eliasafu ọmọ Laeli ni ki o ṣe olori
ile baba awọn ọmọ Gerṣoni.
25 Ati itọju awọn ọmọ Gerṣoni ninu agọ́
ajọ ni, Agọ́, ibori rẹ̀, ati aṣọ-isorọ̀ ti ẹnu-
ọ̀na agọ́ ajọ.
26 Ati aṣọ isorọ̀ ti agbalá, ati aṣọ-tita ti
ẹnu-ọ̀na agbalá, ti mbẹ lẹba agọ́, ati lẹba
pẹpẹ yiká, ati okùn rẹ̀ fun gbogbo iṣẹ-ìsin
rẹ̀.
27 Ati ti Kohati ni idile awọn ọmọ Am-
ramu, ati idile ti awọn ọmọ Ishari, ati idile
ti awọn ọmọ Hebroni, ati idile ti awọn ọmọ
Usieli: wọnyi ni idile awọn ọmọ Kohati.
28 Gẹgẹ bi iye gbogbo awọn ọkọnrin lati
ẹni oṣù kan lọ ati jù bẽ lọ, nwọn jẹ́ ẹgba
mẹrin o le ẹgbẹta, ti nṣe itọju ibimimọ́.
29 Awọn idile ti awọn ọmọ Kohati ni ki
o pagọ́ lẹba agọ́ si iha gusù.
30 Ati Elisafani ọmọ Usieli ni ki o ṣe
olori ile baba awọn idile awọn ọmọ Kohati.
31 Apoti, ati tabeli, ati ọpá-fitila, ati
pẹpẹ wọnni, ati ohun-èlo ibi-mimọ́, eyiti
nwọn fi nṣe iṣẹ alufa, ati aṣọ-tita, ati gbo-
gbo ohun-èlo iṣẹ-ìsin rẹ̀, ni yio jẹ́ ohun
itọju wọn.
32 Eleasari ọmọ Aaroni alufa ni yio si ṣe
olori awọn olori awọn ọmọ Lefi, on ni yio
si ma ṣe itọju awọn ti nṣe itọju ibi-mimọ́.
33 Ti Merari ni idile awọn ọmọ Mali,
ati idile awọn ọmọ Muṣi: wọnyi ni idile
Merari.
34 Ati awọn ti a kà ninu wọn, gẹgẹ bi
iye gbogbo awọn ọkọnrin, lati ọmọ oṣù kan
lọ ati jù bẽ lọ, nwọn jẹ́ ọgbọkanlelọgbọ̀n.
35 Ati Surieli ọmọ Abihaili ni ki o ṣe
olori ile baba awọn idile Merari; ki nwọn
ki o dó ni ìha agọ́ si ìha ariwa.

Digitized by Google

36 Işẹ itọju awọn ọmọ Merari yio si jẹ́
apáko agọ́, ati ọpá-idabu rẹ̀, ati opó rẹ̀, ati
ihò-ìtẹbọ rẹ̀, ati gbogbo ohun-èlo rẹ̀, ati
gbogbo ohun-èlo ìsin rẹ̀;
37 Ati opó agbalá yiká, ati ihò-ìtẹbọ
wọn, ati ẽkàn wọn, ati okùn wọn.
38 Şugbọn awọn ti o pagọ́ niwaju agọ́
na, si ìha ìla-õrùn, ani niwaju agọ́ ajọ si
ìha ìla-õrùn ni, ki o jẹ́ Mose, ati Aaroni ati
awọn ọmọ rẹ̀, ti nwọn nşe itọju ibi-mimọ́,
fun itọju awọn ọmọ Israeli; alejò ti o ba si
sunmọtosi pipa li a o pa a.
39 Gbogbo awọn ti a kà ninu awọn ọmọ
Lefi, ti Mose ati Aaroni kà nipa aşẹ OLUWA,
gẹgẹ bi idile wọn, gbogbo awọn ọkọnrin
lati ọmọ oşù kan lọ ati jù bẹ̃ lọ, nwọn jẹ́
ẹgba mọkanla.
40 OLUWA si sọ fun Mose pe, Kà gbogbo
awọn akọ́bi ọkọnrin awọn ọmọ Israeli lati
ọmọ oşù kan lọ ati jù bẹ̃ lọ, ki o si gbà iye
orukọ wọn.
41 Ki iwọ ki o si gbà awọn ọmọ Lefi fun
mi (Emi li OLUWA) ni ipò gbogbo awọn
akọ́bi ninu awọn ọmọ Israeli; ati ohun-
ọ̀sin awọn ọmọ Lefi, ni ipò gbogbo awọn
akọ́bi ninu ohun-ọ̀sin awọn ọmọ Israeli.
42 Mose si kà gbogbo awọn akọ́bi ninu
awọn ọmọ Israeli, bi OLUWA ti paşẹ fun u.
43 Ati gbogbo awọn akọ́bi ọkọnrin nipa
iye orukọ, lati ọmọ oşù kan lọ ati jù bẹ̃ lọ
ninu eyiti a kà ninu wọn, jẹ́ ẹgba mọkanla
o le ọrinlugba o dín meje.
44 OLUWA si sọ fun Mose pe,
45 Gbà awọn ọmọ Lefi ni ipò gbogbo
awọn akọ́bi ninu awọn ọmọ Israeli, ati
ohun-ọ̀sin awọn ọmọ Lefi nipò ohun-ọ̀sin
wọn; awọn ọmọ Lefi yio si jẹ́ ti emi; Emi
li OLUWA.
46 Ati fun ìrapada awọn ọrinlugba din
meje ti awọn abọ́bi ninu awọn ọmọ Israeli,
ti nwọn fi jù awọn ọmọ Lefi lọ,
47 Ani ki o gbà şekeli marun-marun li
ori ẹni kọkan, gẹgẹ bi şekeli ibi-mimọ́ ni
ki o gbà wọn; (ogun gera ni şekeli kan):
48 Ki o si fi ninu owo na, ani owo ìra-
pada ti o lé ninu wọn, fun Aaroni ati fun
awọn ọmọ rẹ̀.
49 Mose si gbà owo ìrapada lọwọ awọn
ti o lé lori awọn ti a fi awọn ọmọ Lefi
rasilẹ:
50 Lọwọ awọn akọ́bi awọn ọmọ Israeli
li o gbà owo na; egbeje şekeli o din ma-
rundilogoji, gẹgẹ bi şekeli ibi mimọ́:
51 Mose si fi owo awọn ti a rapada fun
Aaroni ati fun awọn ọmọ rẹ̀, gẹgẹ bi ọ̀rọ
OLUWA, gẹgẹ bi OLUWA ti paşẹ fun Mose.

## ORI 4.

OLUWA si sọ fun Mose ati Aaroni pe,
2 Kà iye awọn ọmọ Kohati kuro ninu
awọn ọmọ Lefi, nipa idile wọn, ile baba
wọn,
3 Lati ẹni ọgbọ̀n ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ,
ani titi di ẹni ãdọta ọdún, gbogbo ẹniti o
wọ̀ inu işẹ-ìsin, lati şe işẹ ninu agọ́ ajọ.
4 Eyi ni yio şe işẹ-ìsin awọn ọmọ Kohati
ninu agọ́ ajọ, niti ohun mimọ́ julọ wọnni:
5 Nigbati ibudó ba si şí siwaju, Aaroni
o wá, ati awọn ọmọ rẹ̀, nwọn o si bọ́ aşọ-
ikele rẹ̀ silẹ, nwọn o si fi i bò apoti ẹrí;
6 Nwọn o fi awọ seali bò o, nwọn o si
nà aşọ kìki alaró bò o, nwọn o si tẹ̀ ọpá nì
bọ̀ ọ.
7 Ati lori tabili àkara ifihàn nì, ki nwon
ki o nà aşọ alaró kan si, ki nwọn ki o si fi
awopọkọ sori rẹ̀, ati şibi ati awokòto, ati
ìgo ohun didà: ati àkara ìgbagbogbo nì ki
o wà lori rẹ̀:
8 Ki nwọn ki o si nà aşọ ododó bò wọn,
ki nwọn ki o si fi awọ seali bò o, ki nwọn
ki o si tẹ̀ ọpá rẹ̀ bọ̀ ọ.
9 Ki nwọn ki o si mú aşọ alaró kan, ki
nwọn ki o si fi bò ọpá-fitila nì, ati fitila
rẹ̀, ati alumagaji rẹ̀, ati awo alumagaji rẹ̀,
ati gbogbo ohunèlo oróro rẹ̀, eyiti nwọn fi
nşe işẹ rẹ̀.
10 Ki nwọn ki o si fi on ati gbogbo ohun-
èlo rẹ̀ sinu awọ seali, ki nwọn ki o si gbé e
lé ori igi.
11 Ati lori pẹpẹ wurà ni ki nwọn ki o
nà aşọ alaró kan si, nwọn o si fi awọ seali
bò o, nwọn o si tẹ̀ ọpá rẹ̀ bọ̀ ọ.
12 Ki nwọn ki o si kó gbogbo ohun-èlo
ìsin, ti nwọn fi nşe işẹ-ìsin ninu ibi-mimọ́,
ki nwọn ki o si fi wọn sinu aşọ alaró kan,
ki nwọn ki o si fi awọ seali bò wọn, ki nwon
ki o si fi wọn kà ori igi.
13 Ki nwọn ki o si kó ẽru kuro lori pẹ-
pẹ, ki nwọn ki o si nà aşọ elesè-aluko kan
bò o.
14 Ki nwọn ki o si fi gbogbo ohun-èlo rẹ̀
ti nwọn fi şe işẹ-ìsin rẹ̀ sori rẹ̀, awo iná, ati
kọkọrọ ẹran, ati ọkọ́-ẽru, ati awokòto, ati
gbogbo ohun-èlo pẹpẹ na; ki nwọn ki o si
nà awọ seali sori rẹ̀, ki nwọn ki o si tẹ ọpá
rẹ̀ bọ̀ ọ.
15 Nigbati Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ ba
pari ati bò ibi-mimọ́ na tán, ati gbogbo
ohun-èlo ibi-mimọ́ na, nigbati ibudó yio ba
şí siwaju; lẹhin eyinì, li awọn ọmọ Kohati
yio wá lati gbé e: şugbọn nwọn kò gbọdọ
fọwọkàn ohun mimọ kan, ki nwọn ki o má

Digitized by Google

ba kú. Wọnyi li ẹrù awọn ọmọ Kohati
ninu agọ́ ajọ.
16 Ohun itọju Eleasari ọmọ Aaroni alufa
si ni oróro fitila, ati turari didùn, ati ẹbọ
ohunjijẹ ìgbagbogbo, ati oróro itasori, ati
itọju agọ́ na gbogbo, ati ti ohun gbogbo ti
mbẹ ninu rẹ̀, ninu ibi-mimọ́ nì, ati ohun-
èlo rẹ̀ na.
17 OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni
pe,
18 Ẹ máṣe ke ẹ̀ya idile awọn ọmọ Koha-
ti kuro lãrin awọn ọmọ Lefi:
19 Ṣugbọn bayi ni ki ẹ ṣe fun wọn, ki
nwọn ki o le yè, ki nwọn ki o má ba kú,
nigbati nwọn ba sunmọ ohun mimọ́ julọ:
ki Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ wọnu-ile, ki
nwọn si yàn wọn olukuluku si iṣẹ rẹ̀ ati si
ẹrù rẹ̀;
20 Ṣugbọn nwọn kò gbọdọ wọle lọ lati
wò ohun mimọ́ ni iṣẹju kan, ki nwọn ki o
má ba kú.
21 OLUWA si sọ fun Mose pe,
22 Kà iye awọn ọmọ Gerṣoni pẹlu, gẹgẹ
bi ile baba wọn, nipa idile wọn;
23 Lati ẹni ọgbọ̀n ọdún lọ ati jù bẽ lọ
titi di ẹni ãdọta ọdún ni ki o kaye wọn;
gbogbo awọn ti o wọnu-ile lọ lati ṣe iṣẹ-ìsin,
lati ṣe iṣẹ ninu agọ́ ajọ.
24 Eyi ni iṣẹ-ìsin idile awọn ọmọ Gerṣo-
ni, lati sìn ati lati rù ẹrù:
25 Awọn ni yio si ma rù aṣọ-ikele agọ́,
ati agọ́ ajọ, ibori rẹ̀, ati ibori awọ seali ti
mbẹ lori rẹ̀, ati aṣọ-tita fun ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ;
26 Ati aṣọ-isorọ̀ ti agbalá, ati aṣọ-tita fun
ẹnu-ọ̀na agbalá, ti mbẹ lẹba agọ́ ati lẹba
pẹpẹ yiká, ati okùn wọn, ati gbogbo ohun-
èlo iṣẹ-ìsin wọn, ati ohun gbogbo ti a ṣe
fun wọn; bẹ̃ni nwọn o ma sìn.
27 Nipa aṣẹ Aaroni ati ti awọn ọmọ rẹ̀
ni ki gbogbo iṣẹ-ìsin awọn ọmọ Gerṣoni jẹ́,
ni gbogbo ẹrù wọn, ati ni gbogbo iṣẹ-ìsin
wọn: ki ẹnyin si yàn wọn si itọju gbogbo
ẹrù wọn.
28 Eyi ni iṣẹ-ìsin idile awọn ọmọ Gerṣo-
ni ninu agọ́ ajọ: ki itọju wọn ki o si wà li
ọwọ́ Itamari ọmọ Aaroni alufa.
29 Ati awọn ọmọ Merari, ki iwọ ki o kà
wọn gẹgẹ bi idile wọn, nipa ile baba wọn;
30 Lati ẹni ọgbọ̀n ọdún lọ ati jù bẽ lọ
ani titi di ẹni ãdọta ọdún ni ki iwọ ki o kà
wọn, gbogbo ẹniti o wọ̀ inu iṣẹ-ìsin na lati
ṣe iṣẹ ninu agọ́ ajọ́.
31 Eyi si ni itọju ẹrù wọn, gẹgẹ bi gbo-
gbo iṣẹ-ìsin wọn ninu agọ́ ajọ; awọn apáko
agọ́, ati ọpá-idabu rẹ̀, ati opó rẹ̀, ati ìhò-
ìtẹbọ rẹ̀,
32 Ati opó agbalá yiká, ati ihò-ìtẹbọ
wọn, ati ẽkàn wọn, ati okùn wọn, pẹlu
ohun-èlo wọn gbogbo, ati pẹlu ohun-ìsin
wọn gbogbo: li orukọ li orukọ ni ki ẹnyin
ki o kà ohun-èlo ti iṣe itọju ẹrù wọn.
33 Eyi ni iṣẹ-ìsin idile awọn ọmọ Merari,
gẹgẹ bi iṣẹ-ìsin wọn gbogbo, ninu agọ́ ajọ,
labẹ Itamari ọmọ Aaroni alufa.
34 Mose ati Aaroni ati awọn olori ijọ
awọn enia si kà awọn ọmọ Kohati nipa
idile wọn, ati gẹgẹ bi ile baba wọn,
35 Lati ẹni ọgbọ̀n ọdún lọ ati jù bẽ lọ
ani titi di ẹni ãdọta ọdún, gbogbo ẹniti o
wọ̀ inu iṣẹ-ìsin na fun iṣẹ ninu agọ́ ajọ:
36 Awọn ti a si kà ninu wọn nipa idile
wọn jẹ́ ẹgbẹrinla o din ãdọta.
37 Wọnyi li awọn ti a kà ni idile awọn
ọmọ Kohati, gbogbo awọn ti o le ṣe iṣẹ-ìsin
ninu agọ́ ajọ, ti Mose ati Aaroni kà, gẹgẹ
bi aṣẹ OLUWA nipa ọwọ́ Mose.
38 Awọn ti a si kà ninu awọn ọmọ Ger-
ṣoni, nipa idile wọn, ati gẹgẹ bi ile baba
wọn,
39 Lati ẹni ọgbọ̀n ọdún lọ ati jù bẽ lọ
ani titi di ẹni ãdọta ọdún, gbogbo ẹniti
o wọ̀ inu iṣẹ-ìsin na, fun iṣẹ ninu agọ́
ajọ,
40 Ani awọn ti a kà ninu wọn, nipa
idile wọn, gẹgẹ bi ile baba wọn, jẹ́ ẹgbẹta-
la o le ọgbọ̀n.
41 Wọnyi li awọn ti a kà ni idile awọn
ọmọ Gerṣoni, gbogbo awọn ti o ṣe iṣẹ-ìsin
ninu agọ́ ajọ, ti Mose ati Aaroni kà gẹgẹ bi
aṣẹ OLUWA.
42 Awọn ti a si kà ni idile awọn ọmọ
Merari, nipa idile wọn, gẹgẹ bi ile baba
wọn,
43 Lati ẹni ọgbọ̀n ọdún lọ ati jù bẽ lọ,
ani titi di ẹni ãdọta ọdún, gbogbo ẹniti o
wọ̀ inu iṣẹ-ìsin na, fun iṣẹ ninu agọ́ ajọ,
44 Ani awọn ti a kà ninu wọn nipa idile
wọn jẹ́ ẹgbẹrindilogun.
45 Wọnyi li awọn ti a kà ninu idile
awọn ọmọ Merari, ti Mose ati Aaroni kà
gẹgẹ bi aṣẹ OLUWA nipa ọwọ́ Mose.
46 Gbogbo awọn ti a kà ninu awọn ọmọ
Lefi, ti Mose ati Aaroni ati awọn olori
Israeli kà, nipa idile wọn, ati gẹgẹ bi ile
baba wọn,
47 Lati ẹni ọgbọ̀n ọdún lọ ati jù bẽ lọ
ani titi di ẹni ãdọta ọdún, gbogbo ẹniti o
wá lati ṣe iṣẹ-ìsin, ati iṣẹ ẹrù ninu agọ́ ajọ,
48 Ani awọn ti a kà ninu wọn, jẹ́ ẹgbẹ-
talelẹgbarin o din ogun.
49 Gẹgẹ bi aṣẹ OLUWA li a kà wọn nipa
ọwọ́ Mose, olukuluku nipa iṣẹ-ìsin rẹ̀, ati

Digitized by Google

gẹgẹ bi ẹrù rẹ̀ : bẹ̃li a ti ọwọ rẹ̀ kà wọn, bi
OLUWA ti fi aṣẹ fun Mose.

## ORI 5.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Paṣẹ fun awọn ọmọ Israeli, ki nwọn
ki o yọ gbogbo adẹ̀tẹ kuro ni ibudó, ati
gbogbo ẹniti o ní isun, ati ẹnikẹni ti o di
alaimọ́ nipa okú :
3 Ati ọkọnrin ati obirin ni ki ẹnyin ki o
yọ kuro, lẹhin ode ibudó ni ki ẹ fi wọn si ;
ki nwọn ki o máṣe sọ ibudó wọn di alaimọ́,
lãrin eyiti Emi ngbé.
4 Awọn ọmọ Israeli si ṣe bẹ̃, nwọn si yọ
wọn sẹhin ibudó : bi OLUWA ti sọ fun
Mose, bẹ̃ li awọn ọmọ Israeli ṣe.
5 OLUWA si sọ fun Mose pe,
6 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Nigbati
ọkọnrin kan tabi obirin kan ba dá ẹ̀ṣẹkẹṣẹ
ti enia ida, ti o ṣe irekọja si OLUWA, ti
oluwarẹ̀ si jẹbi :
7 Nigbana ni ki nwọn ki o jẹwọ ẹ̀ṣẹ ti
nwọn ṣẹ̀ : ki o si san ẹsan ẹ̀ṣẹ rẹ̀ li oju-owo,
ki o si fi idamarun rẹ̀ lé e, ki o si fi i fun
ẹniti on jẹbi rẹ̀.
8 Bi o ba si ṣepe ọkọnrin na kò ní ibatan
kan lati san ẹsan ẹ̀ṣẹ na fun, ki a san ẹsan
na fun OLUWA, ani fun alufa ; pẹlu àgbo
ètutu, ti a o fi ṣètutu fun u.
9 Ati gbogbo ẹbọ agbesọsoke ohun mimọ́
gbogbo ti awọn ọmọ Israeli, ti nwọn mú tọ̀
alufa wá, yio jẹ́ tirẹ̀.
10 Ati ohun mimọ́ olukuluku, ki o jẹ́
tirẹ̀ : ohunkohun ti ẹnikan ba fi fun alufa
ki o jẹ́ tirẹ̀.
11 OLUWA si sọ fun Mose pe,
12 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Bi aya ọkọnrin kan ba yapa, ti
o si ṣẹ̀ ẹ,
13 Ti ọkọnrin kan si bá a dàpọ, ti o si
pamọ́ fun ọkọ rẹ̀, ti o si sin, ti on si di ẹni
ibàjẹ́, ti kò si sí ẹlẹri kan si i, ti a kò si
mú u mọ ọ,
14 Ti ẹmi owú ba dé si i, ti o si njowú
aya rẹ̀, ti obirin na si di ẹni ibàjẹ́ : tabi bi
ẹmi owú ba dé si i, ti o si njowú aya rẹ̀,
ṣugbọn ti on kò di ẹni ibàjẹ́ :
15 Nigbana ni ki ọkọnrin na ki o mú
aya rẹ̀ tọ̀ alufa wá, ki o si mú ọrẹ-ẹbọ rẹ̀
wá fun u, idamẹwa òṣuwọn efa iyẹfun bar-
le ; ki o máṣe dà ororo sori rẹ̀, bẹ̃ni ki o
máṣe fi turari sinu rẹ̀ ; nitoripe ẹbọ ohun-
jijẹ owú ni, ẹbọ ohunjijẹ iranti ni, ti nmú
irekọja wá si iranti.
16 Ki alufa na ki o si mú u sunmọtosi,
ki o mu u duro niwaju OLUWA :
17 Ki alufa ki o si bù omi mimọ́ ninu
ohun-èlo amọ̀ kan ; ati ninu erupẹ ti mbẹ
ni ilẹ agọ́ ni ki alufa ki o bù, ki o si fi i
sinu omi na :
18 Ki alufa ki o si mu obirin na duro
niwaju OLUWA, ki o si ṣí ibori obirin na,
ki o si fi ẹbọ ohunjijẹ iranti na lé e li ọwọ́,
ti iṣe ẹbọ ohunjijẹ owú : ati li ọwọ́ alufa ni
omi kikorò ti imú egún wá yio wà.
19 Alufa na yio si mu u bura, yio si wi
fun obirin na pe, Bi ọkọnrin kò ba bá ọ
dàpọ, bi iwọ kò ba si yàsapakan si ìwa-
aimọ́, labẹ ọkọ rẹ, ki iwọ ki o yeje omi ki-
korò yi ti imú egún wá :
20 Ṣugbọn bi iwọ ba yapa, labẹ ọkọ rẹ,
ti iwọ si di ẹni ibàjẹ́, ti ọkọnrin miran si
bá ọ dàpọ laiṣe ọkọ rẹ :
21 Nigbana ni ki alufa ki o mu ki obirin
na fi èpe bura, ki alufa ki o si wi fun obirin
na pe, Ki OLUWA ki o sọ ọ di ẹni egún, ati
ẹni ifire ninu awọn enia rẹ, nigbati OLUWA
ba mu itan rẹ rà, ti o si mu inu rẹ wú ;
22 Ati omi yi ti nmú egún wá ki o wọ̀
inu rẹ lọ, lati mu inu rẹ wú, ati lati mu
itan rẹ rà : ki obirin na ki o si wipe, Amin,
amin.
23 Ki alufa ki o si kọ egún yi sinu iwé,
ki o si fi omi kikorò na wẹ̀ ẹ nù :
24 Ki o si jẹ ki obirin na ki o mu omi
kikorò na ti imú egún wá : omi na ti imú
egún wá yio si wọ̀ inu rẹ̀ lọ, a si di kikorò.
25 Nigbana li alufa yio gbà ẹbọ ohunjijẹ
owú na li ọwọ́ obirin na, yio si fi ẹbọ ohun-
jijẹ na niwaju OLUWA, yio si ru u lori
pẹpẹ :
26 Ki alufa ki o si bù ikunwọ kan ninu
ẹbọ ohunjijẹ na, ani iranti rẹ̀, ki o si sun u
lori pẹpẹ, lẹhin eyinì ki o jẹ ki obirin na
mu omi na.
27 Nigbati o ba si mu u mu omi na tán,
yio si ṣe, bi o ba ṣe ẹni ibàjẹ́, ti o si ṣẹ̀ ọkọ
rẹ̀, omi ti imú egún wá yio si wọ̀ inu rẹ̀ lọ,
a si di kikorò, inu rẹ̀ a si wú, itan rẹ̀ a si
rà : obirin na a si di ẹni egún lãrin awọn
enia rẹ̀.
28 Bi obirin na kò ba si ṣe ẹni ibàjẹ́,
ṣugbọn ti o mọ́ ; njẹ yio yeje, yio si lóyun.
29 Eyi li ofin owú, nigbati obirin kan
ba yapa labẹ ọkọ rẹ̀, ti o si di ẹni ibàjẹ́ ;
30 Tabi nigbati ẹmi owú ba dé si ọkọ
kan, ti o ba si njowú obirin rẹ̀ ; nigbana
yio mu obirin na duro niwaju OLUWA, ki
alufa ki o si ṣe gbogbo ofin yi si i.
31 Nigbana li ọkọnrin na yio bọ́ kuro
ninu aiṣedede, obirin na yio si rù aiṣedede
ara rẹ̀.

Digitized by Google

## ORI 6.

OLUWA si sọ fun Mose pe,

2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi fun wọn pe, Nigbati ọkọnrin kan tabi obirin kan ba yà ara wọn sapakan lati ṣe ileri ti Nasiri, lati yà ara wọn si OLUWA:

3 Ki o yà ara rẹ̀ kuro ninu ọti-waini tabi ọti lile; ki o má si ṣe mu ọti-waini kikan, tabi ọti lile ti o kan, ki o má si ṣe mu ọti eso-àjara kan, bẹ̃ni kò gbọdọ jẹ eso-àjara tutù tabi gbigbẹ.

4 Ni gbogbo ọjọ́ ìyasapakan rẹ̀ ni kò gbọdọ jẹ ohun kan ti a fi eso-àjara ṣe, lati kóro rẹ̀ titi dé ẽpo rẹ̀.

5 Ni gbogbo ọjọ́ ileri ìyasapakan rẹ̀, ki abẹ kan máṣe kàn a li ori: titi ọjọ́ wọnni yio fi pé, ninu eyiti o yà ara rẹ̀ si OLUWA, ki o jẹ́ mimọ́, ki o si jẹ ki ìdi irun ori rẹ̀ ki o ma dàgba.

6 Ni gbogbo ọjọ́ ti o yà ara rẹ̀ si OLUWA, on kò gbọdọ sunmọ okú.

7 On kò gbọdọ sọ ara rẹ̀ di alaimọ́ nitori baba rẹ̀, tabi nitori iya rẹ̀, nitori arakọnrin rẹ̀, tabi nitori arabirin rẹ̀, nigbati nwọn ba kú: nitoripe ìyasapakan Ọlọrun rẹ̀ mbẹ li ori rẹ̀.

8 Ni gbogbo ọjọ́ ìyasapakan rẹ̀, mimọ́ li on fun OLUWA.

9 Bi enia kan ba si kú lojiji lẹba ọdọ rẹ̀, ti o ba si bà ori ìyasapakan rẹ̀ jẹ́; nigbana ni ki o fá ori rẹ̀ li ọjọ́ ìwẹnumọ́ rẹ̀, ni ijọ́ keje ni ki o fá a.

10 Ati ni ijọ́ kẹjọ ki o mú àdaba meji, tabi ọmọ ẹiyẹle meji tọ̀ alufa wá, si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ:

11 Ki alufa ki o si rú ọkan li ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ekeji li ẹbọ sisun, ki o si ṣètutu fun u, nitoriti o ṣẹ̀ nipa okú, ki o si yà ori rẹ̀ simimọ́ li ọjọ́ na.

12 Ki o si yà ọjọ́ ìyasapakan rẹ̀ simimọ́ si OLUWA, ki o si mú akọ ọdọ-agutan kan ọlọdún kan wá, fun ẹbọ ẹbi: ṣugbọn ọjọ́ ti o ti ṣaju yio di asan, nitoripe ìyasapakan rẹ̀ bàjẹ́.

13 Eyi si li ofin ti Nasiri, nigbati ọjọ́ ìyasapakan rẹ̀ ba pé: ki a si mú u wa si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ:

14 On o si mú ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ wá fun OLUWA, akọ ọdọ-agutan kan ọlọdún kan alailabùkun fun ẹbọ sisun, ati abo ọdọ-agutan kan ọlọdún kan alailabùkun fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati àgbo kan alailabùkun fun ẹbọ alafia.

15 Ati agbọ̀n àkara alaiwu kan, àkara adidùn iyẹfun daradara ti a fi oróro pò, ati àkara fẹlẹfẹlẹ alaiwu ti a ta oróro si, ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohunmimu wọn.

16 Ki alufa ki o mú wọn wá siwaju OLUWA, ki o si ru ẹbọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ati ẹbọ sisun rẹ̀:

17 Ki o si ru àgbo na li ẹbọ alafia si OLUWA, pẹlu agbọ̀n àkara alaiwu: ki alufa pẹlu ki o si ru ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ ohunmimu rẹ̀.

18 Ki Nasiri na ki o fá ori ìyasapakan rẹ̀ li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, ki o si mú irun ori ìyasapakan rẹ̀ ki o si fi i sinu iná ti mbẹ labẹ ẹbọ alafia na.

19 Ki alufa ki o si mú apá bibọ àgbo na, ati àkara adidùn kan alaiwu kuro ninu agbọ̀n na, ati àkara fẹlẹfẹlẹ kan alaiwu, ki o si fi wọn lé ọwọ́ Nasiri na, lẹhin ìgba ti a fá irun ori ìyasapakan rẹ̀ tán:

20 Ki alufa ki o si fì wọn li ẹbọ fifì niwaju OLUWA: mimọ́ li eyi fun alufa na, pẹlu àiya fifì, ati itan agbesọsoke: lẹhin na Nasiri na le ma mu ọti-waini.

21 Eyi li ofin ti Nasiri ti o ṣe ileri, ati ti ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ si OLUWA fun ìyasapakan rẹ̀ li àika eyiti ọwọ́ on le tẹ̀: gẹgẹ bi ileri ti o ṣe, bẹ̃ni ki o ṣe nipa ofin ìyasapakan rẹ̀.

22 OLUWA si sọ fun Mose pe,

23 Sọ fun Aaroni ati fun awọn ọmọ rẹ̀ pe, Bayi li ẹnyin o ma sure fun awọn ọmọ Israeli; ki ẹ ma wi fun wọn pe,

24 Ki OLUWA ki o busi i fun ọ, ki o si pa ọ mọ́:

25 Ki OLUWA ki o mu oju rẹ̀ mọlẹ si ọ lara, ki o si ṣãnu fun ọ:

26 Ki OLUWA ki o ma bojuwò ọ, ki o si ma fun ọ ni alafia.

27 Bayi ni nwọn o fi orukọ mi sara awọn ọmọ Israeli; emi a si busi i fun wọn.

## ORI 7.

OSI ṣe li ọjọ́ na ti Mose gbé agọ́ na ró tán, ti o si ta oróro si i ti o si yà a simimọ́, ati gbogbo ohun-èlo rẹ̀, ati pẹpẹ na ati gbogbo ohun-èlo rẹ̀, ti o si ta oróro si wọn, ti o si yà wọn simimọ́;

2 Ni awọn ijoye Israeli, awọn olori ile baba wọn, awọn olori ẹya wọnni, ti iṣe olori awọn ti a kà, mú ọrẹ wá:

3 Nwọn si mú ọrẹ-ẹbọ wọn wá siwaju OLUWA, kẹkẹ́-ẹrù mẹfa ti a bò, ati akọmalu mejila: kẹkẹ́-ẹrù kan fun ijoye meji, ati akọmalu kan fun ọkọkan: nwọn si mú wọn wá siwaju agọ́ ajọ.

4 OLUWA si sọ fun Mose pe,

5 Gbà a lọwọ wọn, ki nwọn ki o le jẹ́ ati fi ṣe iṣẹ-ìsin agọ́ ajọ; ki iwọ ki o si fi

Digitized by Google

wọn fun awọn ọmọ Lefi, fun olukuluku
gẹgẹ bi iṣẹ-ìsin rẹ̀.
6 Mose si gbà kẹkẹ́-ẹrù wọnni, ati akọ-
malu, o si fi wọn fun awọn ọmọ Lefi.
7 Kẹkẹ́-ẹrù meji ati akọmalu mẹrin, li o
fi fun awọn ọmọ Gerṣoni, gẹgẹ bi iṣẹ-ìsin wọn:
8 Ati kẹkẹ́-ẹrù mẹrin ati akọmalu mẹjọ
li o fi fun awọn ọmọ Merari, gẹgẹ bi iṣẹ-
ìsin wọn, li ọwọ́ Itamari ọmọ Aaroni alufa.
9 Ṣugbọn kò fi fun awọn ọmọ Kohati:
nitoripe iṣẹ-ìsin ibi-mimọ́ ni ti wọn; li
ohun ti nwọn o ma fi ejika rù.
10 Awọn olori si mú ọrẹ wá fun ìyasi-
mimọ́ pẹpẹ li ọjọ́ ti a ta oróro si i, ani
awọn olori mú ọrẹ-ẹbọ wọn wá siwaju pẹpẹ
na.
11 OLUWA si wi fun Mose pe, Ki nwọn
ki o ma mú ọrẹ-ẹbọ wọn wá, olukuluku
olori li ọjọ́ tirẹ̀ fun ìyasimimọ́ pẹpẹ.
12 Ẹniti o si mú ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ wá li ọjọ́
kini ni Naṣoni ọmọ Amminadabu, ti ẹ̀ya
Juda:
13 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ si jẹ́ awopọkọ kan ti
fadakà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awokòto
kan ti fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli
ibi-mimọ́; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò, fun ẹbọ ohunjijẹ;
14 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari;
15 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun;
16 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ;
17 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan: eyi li ọrẹ-ẹbọ
ti Naṣoni ọmọ Amminadabu.
18 Li ọjọ́ keji ni Netaneeli ọmọ Suari,
olori ti Issakari mú ọrẹ wá:
19 On múwa fun ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ awopọkọ
kan ti fadakà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awo-
kòto kan ti fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi
ṣekeli ibi-mimọ́; mejeji wọn kún fun iyẹ-
fun daradara ti a fi oróro pò, fun ẹbọ ohun-
jijẹ:
20 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari;
21 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun;
22 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ;
23 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu meji,
àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-agutan
marun ọlọdún kan: eyi li ọrẹ-ẹbọ ti Neta-
neeli ọmọ Suari.
24 Li ọjọ́ kẹta Eliabu ọmọ Heloni, olori
awọn ọmọ Sebuluni:
25 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awọpọkọ kan ti fada-
kà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awokòto kan ti
fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli ibi-
mimọ́; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò, fun ẹbọ ohunjijẹ;
26 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari;
27 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun;
28 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ;
29 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan: eyi li ọrẹ-ẹbọ
ti Eliabu ọmọ Heloni.
30 Li ọjọ́ kẹrin Elisuri ọmọ Ṣedeuri,
olori awọn ọmọ Reubeni;
31 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ awopọkọ kan ti fada-
kà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awokòto kan ti
fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli ibi-
mimọ́; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò fun ẹbọ ohunjijẹ;
32 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari;
33 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun;
34 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ;
35 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan: eyi li ọrẹ-ẹbọ
ti Elisuri ọmọ Ṣedeuri.
36 Li ọjọ́ karun Ṣelumieli ọmọ Suri-
ṣaddai, olori awọn ọmọ Simeoni:
37 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awopọkọ kan ti fada-
kà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awokòto kan ti
fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli ibi-
mimọ́; mejeji wọn kún fun iyẹfun daradara
ti a fi oróro pò fun ẹbọ ohunjijẹ;
38 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari;
39 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun;
40 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ;
41 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan: eyi li ọrẹ-ebọ
Ṣelumieli ọmọ Ṣuriṣaddai.
42 Li ọjọ́ kẹfa Eliasafu ọmọ Deueli,
olori awọn ọmọ Gadi:
43 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awopọkọ kan ti fada-
kà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awo-kòto kan
ti fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli ibi-
mimọ́; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò fun ẹbọ ohunjijẹ;
44 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari;
45 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun;

Digitized by Google

46 Akọ ewure kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ;
47 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan : eyi li ọrẹ-ẹbọ
Eliasafu ọmọ Deueli.
48 Li ọjọ́ keje Eliṣama ọmọ Ammihudu,
olori awọn ọmọ Efraimu :
49 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awopọkọ kan ti fadakà,
ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awo-kòto kan ti
fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli ibi-
mimọ́ ; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò, fun ẹbọ ohunjijẹ ;
50 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari ;
51 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun ;
52 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ;
53 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan : eyi li ọrẹ-ẹbọ
Eliṣama ọmọ Ammihudu.
54 Li ọjọ́ kẹjọ Gamalieli ọmọ Pedasuri,
olori awọn ọmọ Manasse :
55 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awopọkọ kan ti fada-
kà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awo-kòto kan
ti fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli ibi-
mimọ́ ; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti fi oróro pò, fun ẹbọ ohunjijẹ ;
56 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari ;
57 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun ;
58 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ;
59 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan : eyi li ọrẹ-ẹbọ
ti Gamalieli ọmọ Pedasuri.
60 Li ọjọ́ kẹsan Abidani ọmọ Gideoni,
olori awọn ọmọ Benjamini :
61 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awopọkọ kan ti fada-
kà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awo-kòto kan
ti fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli ibi-
mimọ́ ; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò, fun ẹbọ ohunjijẹ ;
62 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari ;
63 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun ;
64 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ;
65 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbe marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan : eyi li ọrẹ-ẹbọ
ti Abidani ọmọ Gideoni.
66 Li ọjọ́ kẹwá ni Ahieseri ọmọ Ammi-
ṣaddai, olori awọn ọmọ Dani :
67 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awopọkọ kan ti fada-
kà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awo-kòto kan
ti fadakà ìwọn ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli
ibi-mimọ́ ; mejeji wọn kún fun iyẹfun
daradara ti a fi oróro pò, fun ẹbọ ohunjijẹ :
68 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari ;
69 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ si-
sun ;
70 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ;
71 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan : eyi li ọrẹ-ẹbọ ti
Ahieseri ọmọ Ammiṣaddai.
72 Li ọjọ́ kọkanla Pagieli ọmọ Okrani,
olori awọn ọmọ Aṣeri :
73 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awopọkọ kan ti fada-
kà, ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awo-kòto kan
ti fadakà ìwọn ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli
ibi-mimọ́ ; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò, fun ẹbọ ohunjijẹ ;
74 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari ;
75 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun ;
76 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ;
77 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbo marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan : eyi li ọrẹ-ẹbọ
ti Pagieli ọmọ Okrani.
78 Li ọjọ́ kejila Ahira ọmọ Enani, olori
awọn ọmọ Naftali :
79 Ọrẹ-ẹbọ tirẹ̀ jẹ́ awopọkọ kan ti fadakà,
ìwọn rẹ̀ jẹ́ ãdoje ṣekeli, awo-kòto kan ti
fadakà ãdọrin ṣekeli, gẹgẹ bi ṣekeli ibi-
mimọ́ ; mejeji wọn kún fun iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò, fun ebọ ohunjijẹ ;
80 Ṣibi kan ìwọn ṣekeli mẹwa wurà, o
kún fun turari ;
81 Ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, akọ
ọdọ-agutan kan ọlọdún kan, fun ẹbọ sisun ;
82 Akọ ewurẹ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ ;
83 Ati fun ẹbọ ti ẹbọ alafia, akọmalu
meji, àgbọ marun, obukọ marun, akọ ọdọ-
agutan marun ọlọdún kan : eyi li ọrẹ-ẹbọ
ti Ahira ọmọ Enani.
84 Eyi ni ìyasimimọ́ pẹpẹ, li ọjọ́ ti a ta
oróro si i, lati ọwọ́ awọn olori Israeli wá :
awopọkọ fadakà mejila, awokòto fadakà
mejila, ṣibi wurà mejila :
85 Awopọkọ fadakà kọkan jẹ́ ãdoje ṣe-
keli : awokòto kọkan jẹ́ ãdọrin : gbogbo
ohun-èlo fadakà jẹ́ egbejila ṣekeli, gẹgẹ bi
ṣekeli ibi-mimọ́ ;
86 Ṣibi wurà jẹ́ mejila, nwọn kún fun
turari, ṣibi kọkan jẹ́ ṣekeli mẹwa gẹgẹ bi

Digitized by Google

ṣekeli ibi-mimọ́; gbogbo wurà agọ́ na jẹ́
ọgọfa ṣekeli.
87 Gbogbo akọmalu fun ẹbọ sisun jẹ́
ẹgbọrọ akọmalu mejila, àgbo mejila, akọ
ọdọ-agutan ọlọdún kan mejila, pẹlu ẹbọ
ohunjijẹ wọn: ati akọ ewurẹ fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ,
mejila.
88 Ati gbogbo akọmalu fun ẹbọ ti ẹbọ
alafia jẹ́ akọmalu mẹrinlelogun, àgbo ọgọta,
obukọ ọgọta, akọ ọdọ-agutan ọlọdún kan
ọgọta. Eyi ni ìyasimimọ́ pẹpẹ, lẹhin igbati
a ta oróro si i.
89 Nigbati Mose si wọ̀ inu agọ́ ajọ lọ
lati bá a (Ọlọrun) sọ̀rọ, nigbana li o gbọ́
Ohùn ti nfọ̀ si i lati ori itẹ́-ãnu nì wá ti
mbẹ lori apoti ẹrí, lati agbedemeji awọn
kerubu meji nì wá: o si bá a sọ̀rọ.

## ORI 8.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun Aaroni, ki o si wi fun u pe,
Nigbati iwọ ba tàn fitila, ki fitila mejeje na
ki o ma tàn imọlẹ lori ọpá-fitila.
3 Aaroni si ṣe bẽ; o tàn fitila wọnni lori
ọpá-fitila na, bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose.
4 Iṣẹ ọpá-fitila na yi si jẹ́ ti wurà lilù;
titi dé isalẹ rẹ̀, titi dé itanna rẹ̀, o jẹ́ iṣẹ
lulù: gẹgẹ bi apẹrẹ ti OLUWA fihàn Mose,
bẽli o ṣe ọpá-fitila na.
5 OLUWA si sọ fun Mose pe,
6 Yọ awọn ọmọ Lefi kuro ninu awọn
ọmọ Israeli, ki o si wẹ̀ wọn mọ́.
7 Bayi ni ki iwọ ki o si ṣe si wọn, lati
wẹ̀ wọn mọ́; Wọ́n omi etutu si wọn lara,
ki nwọn ki o si fá gbogbo ara wọn, ki nwọn
ki o si fọ̀ aṣọ wọn, ki nwọn ki o si wẹ̀ ara
wọn mọ́.
8 Ki nwọn ki o si mú ẹgbọrọ akọmalu
kan pẹlu ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ani iyẹfun dara-
dara ti a fi oróro pò, ati ẹgbọrọ akọmalu
keji ni ki iwọ ki o mú fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ.
9 Ki iwọ ki o si mú awọn ọmọ Lefi wá
siwaju agọ́ ajọ: ki iwọ ki o si pe gbogbo
ijọ awọn ọmọ Israeli jọ pọ̀:
10 Ki iwọ ki o si mú awọn ọmọ Lefi wá
siwaju OLUWA: ki awọn ọmọ Israeli ki o
si fi ọwọ́ wọn lé awọn ọmọ Lefi.
11 Ki Aaroni ki o si mú awọn ọmọ Lefi
wá siwaju OLUWA, bi ọrẹ fifì lati ọdọ awọn
ọmọ Israeli wá, ki nwọn ki o le ma ṣe iṣẹ-
ìsin OLUWA.
12 Ki awọn ọmọ Lefi ki o si fi ọwọ́ wọn
lé ori ẹgbọrọ akọmalu wọnni: ki iwọ ki o
si ru ọkan li ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ekeji li ẹbọ sisun
si OLUWA, lati ṣètutu fun awọn ọmọ Lefi.
13 Ki iwọ ki o si mu awọn ọmọ Lefi duro
niwaju Aaroni, ati niwaju awọn ọmọ rẹ̀, ki
o si mú wọn wá li ọrẹ fifì fun OLUWA.
14 Bẽni ki iwọ ki o yà awọn ọmọ Lefi
sọ̀tọ kuro lãrin awọn ọmọ Israeli: awọn
ọmọ Lefi yio si jẹ́ ti emi.
15 Lẹhin eyinì li awọn ọmọ Lefi yio ma
wọ̀ inu ile lọ lati ṣe iṣẹ-ìsin agọ́ ajọ: ki iwọ
ki o si wẹ̀ wọn mọ́, ki o si mú wọn wá li
ọrẹ fifì.
16 Nitoripe patapata li a fi wọn fun mi
ninu awọn ọmọ Israeli; ni ipò gbogbo awọn
ti o ṣí inu, ani gbogbo akọ́bi ninu awọn ọmọ
Israeli, ni mo gbà wọn fun ara mi.
17 Nitoripe ti emi ni gbogbo akọ́bi ninu
awọn ọmọ Israeli, ati ti enia ati ti ẹran: li
ọjọ́ ti mo kọlù gbogbo akọ́bi ni ilẹ Egipti
ni mo ti yà wọn simimọ́ fun ara mi.
18 Emi si ti gbà awọn ọmọ Lefi dipò
gbogbo akọ́bi ninu awọn ọmọ Israeli.
19 Emi si fi awọn ọmọ Lefi fun Aaroni
ati fun awọn ọmọ rẹ̀ li ọrẹ lati inu awọn
ọmọ Israeli wá, lati ma ṣe iṣẹ-ìsin awọn
ọmọ Israeli ninu agọ́ ajọ, ati lati ma ṣètutu
fun awọn ọmọ Israeli: ki àrun má ba sí
ninu awọn ọmọ Israeli, nigbati awọn ọmọ
Israeli ba sunmọ ibi-mimọ́.
20 Bayi ni Mose, ati Aaroni, ati gbogbo
ijọ awọn ọmọ Israeli, ṣe si awọn ọmọ Lefi:
gẹgẹ bi gbogbo eyiti OLUWA paṣẹ fun Mose
niti awọn ọmọ Lefi, bẽli awọn ọmọ Israeli
ṣe si wọn.
21 Awọn ọmọ Lefi si wẹ̀ ara wọn mọ́
kuro ninu ẹ̀ṣẹ, nwọn si fọ̀ aṣọ wọn; Aaroni
si mú wọn wá li ọrẹ fifì siwaju OLUWA:
Aaroni si ṣètutu fun wọn lati wẹ̀ wọn
mọ́.
22 Lẹhin eyinì ni awọn ọmọ Lefi si wọle
lọ lati ṣe iṣẹ-ìsin ninu agọ́ ajọ niwaju
Aaroni, ati niwaju awọn ọmọ rẹ̀: bi OLUWA
ti paṣẹ fun Mose niti awọn ọmọ Lefi, bẽni
nwọn ṣe si wọn.
23 OLUWA si sọ fun Mose pe,
24 Eyi ni ti awọn ọmọ Lefi: lati ẹni
ọdún mẹdọgbọ̀n lọ ati jù bẽ lọ ni ki nwọn
ki o ma wọle lọ lati ṣe iṣẹ-ìsin ninu agọ́
ajọ.
25 Ati lati ẹni ãdọta ọdún ni ki nwọn
ki o ṣiwọ iṣẹ-ìsin, ki nwọn ki o má si ṣe
sìn mọ́;
26 Bikoṣepe ki nwọn ki o ma ṣe iranṣẹ
pẹlu awọn arakọnrin wọn ninu agọ́ ajọ,
lati ma ṣe itọju, ki nwọn ki o má si ṣe iṣẹ-
ìsin mọ́. Bayi ni ki iwọ ki o ṣe si awọn
ọmọ Lefi niti itọju wọn.

Digitized by Google

## ORI 9.

OLUWA si sọ fun Mose ni ijù Sinai, li
oṣù kini ọdún keji ti nwọn ti ilẹ Egipti
jade wá, wipe,
2 Ki awọn ọmọ Israeli ki o si ma pa ajọ
irekọja mọ́ li akokò rẹ̀.
3 Li ọjọ́ kẹrinla oṣù yi, li aṣalẹ, ni ki
ẹnyin ki o ma ṣe e li akokò rẹ̀: gẹgẹ bi aṣẹ
rẹ̀ gbogbo, ati gẹgẹ bi ìlana rẹ̀ gbogbo, ni
ki ẹnyin ki o pa a mọ́.
4 Mose si sọ fun awọn ọmọ Israeli ki
nwọn ki o ma pa ajọ irekọja mọ́:
5 Nwọn si ṣe ajọ irekọja li ọjọ́ kẹrinla,
oṣù kini, li aṣalẹ ni ijù Sinai: gẹgẹ bi
gbogbo eyiti OLUWA paṣẹ fun Mose, bẹ̃li
awọn ọmọ Israeli ṣe.
6 Awọn ọkọnrin kan wà ti nwọn ti ipa
okú ọkọnrin kan di alaimọ́, nwọn kò si le
ṣe ajọ irekọja li ọjọ́ na: nwọn si wá siwaju
Mose ati siwaju Aaroni li ọjọ́ na:
7 Awọn ọkọnrin na si wi fun u pe, Awa
ti ipa okú ọkọnrin kan di alaimọ́: nitori
kili a o ṣe fàsẹhin ti awa ki o le mú ọrẹ-
ẹbọ OLUWA wá li akokò rẹ̀ pẹlu awọn ọmọ
Israeli?
8 Mose si wi fun wọn pe, Ẹ duro na;
ki emi ki o le gbọ́ aṣẹ ti OLUWA yio pa niti
nyin.
9 OLUWA si sọ fun Mose pe,
10 Sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Bi ẹni-
kẹni ninu nyin, tabi ninu iran nyin, ba ti
ipa okú di alaimọ́, tabi bi o ba wà li ọ̀na
àjo jijìn réré, sibẹ̀ on o pa ajọ irekọja mọ́
fun OLUWA.
11 Li ọjọ́ kẹrinla oṣù keji li aṣalẹ ni ki
nwọn ki o pa a mọ́; ki nwọn si fi àkara
alaiwu jẹ ẹ ati ewebẹ kikorò:
12 Ki nwọn ki o máṣe kùsilẹ ninu rẹ̀ titi
di owurọ̀, bẹ̃ni nwọn kò gbọdọ fọ́ egungun
rẹ̀ kan: gẹgẹ bi gbogbo ìlana irekọja ni ki
nwọn ki o ṣe e.
13 Ṣugbọn ọkọnrin na ti o mọ́ ti kò si
sí li ọ̀na àjo, ti o si fàsẹhin lati pa irekọja
mọ́, ani ọkàn na li a o ke kuro ninu awọn
enia rẹ̀: nitoriti kò mú ọrẹ-ẹbọ OLUWA wá
li akokò rẹ̀, ọkọnrin na yio rù ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
14 Bi alejò kan ba si nṣe atipo lọdọ nyin,
ti o si nfẹ́ pa irekọja mọ́ fun OLUWA; gẹgẹ
bi ìlana irekọja, ati gẹgẹ bi aṣẹ rẹ̀, ni ki o
ṣe bẹ̃: ìlana kan ni ki ẹnyin ki o ní, ati fun
alejò, ati fun ibilẹ.
15 Ati li ọjọ́ ti a gbé agọ́ ró awọsanma si
bò agọ́ na, eyinì ni, agọ́ ẹrí: ati li alẹ o si
hàn lori agọ́ na bi iná, titi o fi di owurọ̀.
16 Bẹ̃li o si ri nigbagbogbo: awọsanma
bò o, ati oye iná li oru.
17 Nigbati awọsanma ba ká soke kuro
lori agọ́ na, lẹhin na awọn ọmọ Israeli a si
ṣí: nibiti awọsanma ba si duro, nibẹ̀ li
awọn ọmọ Israeli idó si.
18 Nipa aṣẹ OLUWA awọn ọmọ Israeli a
ṣí, nipa aṣẹ OLUWA nwọn a si dó: ni gbo-
gbo ọjọ́ ti awọsanma ba simi lori agọ́ na,
nwọn a dó.
19 Nigbati awọsanma ba si pẹ li ọjọ́
pupọ̀ lori agọ́ na, awọn ọmọ Israeli a si ma
ṣe afiyesi aṣẹ OLUWA, nwọn ki si iṣí.
20 Nigba miran awọsanma a wà li ọjọ́
diẹ lori agọ́ na; nigbana gẹgẹ bi aṣẹ OLU-
WA nwọn a dó, gẹgẹ bi aṣẹ OLUWA nwọn a
si ṣí.
21 Nigba miran awọsanma a duro lati
alẹ titi di owurọ̀; nigbati awọsanma si ṣí
soke li owurọ̀, nwọn a ṣí: iba ṣe li ọsán
tabi li oru, ti awọsanma ba ká soke, nwọn
a ṣí.
22 Bi ijọ́ meji ni, tabi oṣù kan, tabi
ọdún kan, ti awọsanma ba pẹ lori agọ́ na,
ti o simi lé e, awọn ọmọ Israeli a dó, nwọn
ki si iṣí: ṣugbọn nigbati o ba ká soke, nwọn
a ṣí.
23 Nipa aṣẹ OLUWA nwọn a dó, ati nipa
aṣẹ OLUWA nwọn a ṣí: nwọn a ma ṣe afi-
yesi aṣẹ OLUWA, gẹgẹ bi ọ̀rọ OLUWA nipa
ọwọ́ Mose.

## ORI 10.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Iwọ ṣe ipè fadakà meji; iṣẹ-ọnà lilù
ni ki o ṣe wọn: iwọ o si ma fi wọn pè ajọ,
iwọ o si ma fi wọn ṣí ibudó.
3 Nigbati nwọn ba fun wọn, ki gbogbo
ijọ ki o pé sọdọ rẹ li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ.
4 Bi o ba ṣepe ipè kan ni nwọn fun,
nigbana ni ki awọn ijoye, olori ẹgbẹgbẹrun
enia Israeli, ki o pejọ sọdọ rẹ.
5 Nigbati ẹnyin ba si fun ipè idagiri,
nigbana ni ki awọn ibudó ti o wà ni ìha
ìla-õrùn ki o ṣí siwaju.
6 Nigbati ẹnyin ba si fun ipè idagiri ni-
gba keji, nigbana ni ki awọn ibudó ti o wà
ni ìha gusù ki o ṣí siwaju: ki nwọn ki o si
fun ipè idagiri ṣiṣi wọn.
7 Ṣugbọn nigbati a o ba pè ijọ pọ̀, ki ẹ
fun ipè, ṣugbọn ẹ kò gbọdọ fun ti idagiri.
8 Awọn ọmọ Aaroni, awọn alufa, ni ki
o si fun ipè na; ki nwọn ki o si ma ṣe
ìlana lailai fun nyin ni iran-iran nyin.
9 Bi ẹnyin ba si lọ si ogun ni ilẹ nyin
lọ ipade awọn ọtá ti nni nyin lara, nigbana

Digitized by Google

ni ki ẹnyin ki o fi ipè fun idagiri; a o si
ranti nyin niwaju OLUWA Ọlọrun nyin, a
o si gbà nyin lọwọ awọn ọtá nyin.
10 Li ọjọ̀ ayọ̀ nyin pẹlu, ati li ajọ nyin,
ati ni ìbẹrẹ oṣù nyin, ni ki ẹnyin ki o fun
ipè sori ẹbọ sisun nyin, ati sori ẹbọ ti ẹbọ
alafia nyin; ki nwọn ki o le ma ṣe iranti
fun nyin niwaju Ọlọrun nyin: Emi ni
OLUWA Ọlọrun nyin.
11 O si ṣe li ogun ọjọ́ oṣù keji, li ọdún
keji, ni awọsanma ká soke kuro lori agọ́
ẹri.
12 Awọn ọmọ Israeli si dide ìrin wọn
lati ijù Sinai; awọsanma na si duro ni ijù
Parani.
13 Nwọn si bẹ̀rẹsi iṣí gẹgẹ bi aṣẹ OLUWA
nipa ọwọ́ Mose.
14 Ọpágun ibudó awọn ọmọ Juda si kọ́
ṣí gẹgẹ bi ogun wọn: olori ogun rẹ̀ si ni
Naṣoni ọmọ Amminadabu.
15 Olori ogun ẹ̀ya awọn ọmọ Issakari si
ni Netaneli ọmọ Suari.
16 Olori ogun ẹ̀ya awọn ọmọ Sebuluni
ni Eliabu ọmọ Heloni.
17 A si tú agọ́ na palẹ; awọn ọmọ
Gersọni, ati awọn ọmọ Merari ti nrù agọ́ si
ṣí.
18 Ọpágun ibudó Reubeni si ṣí gẹgẹ bi
ogun wọn: Elisuri ọmọ Ṣedeuri si li olori
ogun rẹ̀.
19 Ati olori ogun ẹ̀ya awọn ọmọ Simeoni ni Ṣelumieli ọmọ Suriṣaddai.
20 Ati olori ogun ẹ̀ya awọn ọmọ Gadi ni
Eliasafu ọmọ Deueli.
21 Awọn ọmọ Kohati ti nrù ohun mimọ́
si ṣí: awọn ti iṣaju a si ma gbé agọ́ ró dè
atidé wọn.
22 Ọpágun ibudó awọn ọmọ Efraimu si
ṣí gẹgẹ bi ogun wọn: Eliṣama ọmọ Ammihudu si li olori ogun rẹ̀.
23 Ati olori ogun ẹ̀ya awọn ọmọ Manasse
ni Gamalieli ọmọ Pedasuri.
24 Ati olori ogun ẹ̀ya awọn ọmọ Benjamini ni Abidani ọmọ Gideoni.
25 Ọpágun ibudó awọn ọmọ Dani, ti o
kẹhin gbogbo ibudó, si ṣí gẹgẹ bi ogun wọn:
olori ogun rẹ̀ si ni Ahieseri ọmọ Ammiṣaddai.
26 Ati olori ogun ẹ̀ya awọn ọmọ Aṣeri ni
Pagieli ọmọ Okrani.
27 Ati olori ogun ẹ̀ya awọn ọmọ Naftali
ni Ahira ọmọ Enani.
28 Bayi ni ìrin awọn ọmọ Israeli gẹgẹ
bi ogun wọn; nwọn si ṣí.
29 Mose si wi fun Hobabu, ọmọ Ragueli
ara Midiani, ana Mose pe, Awa nṣí lọ si ibi
ti OLUWA ti wi pe, Emi o fi i fun nyin:
wá ba wa lọ, awa o ṣe ọ li ore: nitoripe
OLUWA sọ̀rọ rere nipa Israeli.
30 On si wi fun u pe, Emi ki yio lọ;
ṣugbọn emi o pada lọ si ilẹ mi, ati sọdọ ará
mi.
31 O si wipe, Máṣe fi wa silẹ, emi bẹ̀ ọ;
iwọ sá mọ̀ pe ni ijù li awa dó si, iwọ o si
ma ṣe oju fun wa.
32 Yio si ṣe, bi iwọ ba bá wa lọ, yio si
ṣe, pe, orekore ti OLUWA ba ṣe fun wa, on
na li awa o ṣe fun ọ.
33 Nwọn si ṣí kuro ni òke OLUWA ni ìrin
ijọ́ mẹta: apoti majẹmu OLUWA si ṣiwaju
wọn ni ìrin ijọ́ mẹta, lati wá ibi isimi fun
wọn.
34 Awọsanma OLUWA mbẹ lori wọn li
ọsán, nigbati nwọn ba ṣí kuro ninu ibudó.
35 O si ṣe, nigbati apoti ẹrí ba ṣí siwaju,
Mose a si wipe, Dide, OLUWA, ki a si tú
awọn ọtá rẹ ká; ki awọn ti o korira rẹ ki
o si salọ kuro niwaju rẹ.
36 Nigbati o ba si simi, on a wipe, Pada,
OLUWA, sọdọ ẹgbẹgbarun awọn enia Israeli.

ORI 11.

AWỌN enia na nṣe irahùn, nwọn nsọ
ohun buburu li etí OLUWA: nigbati
OLUWA si gbọ́ ọ, ibinu rẹ̀ si rú; iná OLUWA si ràn ninu wọn, o si run awọn ti o wà
li opin ibudó na.
2 Awọn enia na si kigbe tọ̀ Mose lọ;
nigbati Mose si gbadura si OLUWA, iná na
si rẹlẹ.
3 O si pè orukọ̀ ibẹ̀ na ni Tabera: nitoriti iná OLUWA jó lãrin wọn.
4 Awọn adalú ọ̀pọ enia ti o wà pẹlu wọn
ṣe ifẹkufẹ: awọn ọmọ Israeli pẹlu si tun
sọkun wipe, Tani yio fun wa li ẹran jẹ?
5 Awa ranti ẹja, ti awa ti njẹ ni Egipti
li ọfẹ; ati apálà, ati bàra, ati ewebẹ, ati
alubọsa, ati eweko:
6 Ṣugbọn nisisiyi ọkàn wa gbẹ: kò sí
ohun kan rára, bikọṣe manna yi niwaju
wa.
7 Manna na si dabi irugbìn korianderi,
àwọ rẹ̀ si dabi àwọ okuta-bedeliumu.
8 Awọn enia na a ma lọ kakiri, nwọn a
si kó o, nwọn a si lọ̀ ọ ninu ọlọ, tabi nwọn
a si gún u ninu odó, nwọn a si sè e ninu
ìkoko, nwọn a si fi din àkara: itọwò rẹ̀ si
ri bi itọwò àkara oróro.
9 Nigbati ìri ba si sẹ̀ si ibudó li oru,
manna a bọ́ si i.
10 Nigbana ni Mose gbọ́, awọn enia nsọkun ni idile wọn, olukuluku li ẹnu-ọ̀na agọ́

Digitized by Google

tirẹ̀ : ibinu OLUWA si rú si wọn gidigidi ;
o si buru loju Mose.
11 Mose si wi fun OLUWA pe, Nitori
kini iwọ fi npọ́n iranṣẹ rẹ loju ? nitori kili
emi kò si ṣe ri ore-ọfẹ li oju rẹ, ti iwọ fi dì
ẹrù gbogbo enia yi lé mi ?
12 Iṣe emi li o lóyun gbogbo enia yi ?
iṣe emi li o bi wọn, ti iwọ fi wi fun mi pe,
Ma gbé wọn lọ li õkan-aiya rẹ, bi baba iti
igbé ọmọ ọmú, si ilẹ ti iwọ ti bura fun
awọn baba wọn.
13 Nibo li emi o gbé ti mú ẹran wá fi
fun gbogbo enia yi ? nitoriti nwọn nsọkun
si mi wipe, Fun wa li ẹran, ki awa ki o jẹ.
14 Emi nikan kò le rù gbogbo awọn enia
yi, nitoriti nwọn wuwo jù fun mi.
15 Ati bi bayi ni iwọ o ṣe si mi, emi bẹ̀
ọ, pa mi kánkan, bi mo ba ri ore-ọfẹ li oju
rẹ ; má si ṣe jẹ ki emi ri òṣi mi.
16 OLUWA si sọ fun Mose pe, Pe ãdọrin
ọkọnrin ninu awọn àgba Israeli jọ sọdọ mi,
ẹniti iwọ mọ̀ pe, nwọn ṣe àgba awọn enia,
ati olori wọn ; ki o si mú wọn wá si agọ́
ajọ, ki nwọn ki o si duro nibẹ̀ pẹlu rẹ.
17 Emi o si sọkalẹ wá, emi o si bá ọ
sọ̀rọ nibẹ̀ : emi o si mú ninu ẹmi ti mbẹ
lara rẹ, emi o si fi i sara wọn ; nwọn o si
ma bá ọ rù ẹrù awọn enia na, ki iwọ ki o
máṣe nikan rù u.
18 Ki iwọ ki o si wi fun awọn enia na
pe, Ẹ yà ara nyin simimọ́ dè ọla, ẹnyin o
si jẹ ẹran ; nitoriti ẹnyin sọkun li etí OLU-
WA, wipe, Tani yio fun wa li ẹran jẹ? o sá
dara fun wa ni Egipti : nitorina ni OLUWA
yio ṣe fun nyin li ẹran, ẹnyin o si jẹ.
19 Ẹ ki o jẹ ni ijọ́ kan, tabi ni ijọ́ meji,
tabi ni ijọ́ marun, bẹ̃ni ki iṣe ijọ́ mẹwa, ta-
bi ogún ọjọ́ ;
20 Ṣugbọn li oṣù kan tọ̀tọ, titi yio fi yọ
jade ni ihò-imu nyin, ti yio si fi sú nyin :
nitoriti ẹnyin gàn OLUWA ti mbẹ lãrin
nyin, ẹnyin si sọkun niwaju rẹ̀, wipe, Ẽṣe ti
awa fi jade lati Egipti wá ?
21 Mose si wipe, Awọn enia na, lãrin
awọn ẹniti emi wà, jẹ́ ọgbọ̀n ọkẹ ẹlẹsẹ̀ ; iwọ
si wipe, Emi o fun wọn li ẹran, ki nwọn ki
o le ma jẹ li oṣù kan tọ̀tọ̀.
22 Agbo-ẹran tabi ọwọ́-ẹran ni ki a pa
fun wọn, lati tó fun wọn ni ? tabi gbogbo
ẹja okun li a o kójọ fun wọn lati tó fun
wọn ?
23 OLUWA si sọ fun Mose pe, Ọwọ́ OLU-
WA ha kúru bi ? iwọ o ri i nisisiyi bi ọ̀rọ
mi yio ṣẹ si ọ, tabi bi ki yio ṣẹ.
24 Mose si jade lọ, o si sọ ọ̀rọ OLUWA
fun awọn enia : o si pe ãdọrin ọkọnrin ni-
nu awọn àgba enia jọ, o si mu wọn duro yi
agọ́ ká.
25 OLUWA si sọkalẹ wá ninu awọsanma,
o si bá a sọ̀rọ, o si mú ninu ẹmi ti o wà la-
ra rẹ̀, o si fi i sara awọn ãdọrin àgba na : o
si ṣe, nigbati ẹmi na bà lé wọn, nwọn si
sọtẹlẹ, ṣugbọn nwọn kò ṣe bẹ̃ mọ́.
26 Ṣugbọn o kù meji ninu awọn ọkọnrin
na ni ibudó, orukọ ekini a ma jẹ́ Eldadi,
orukọ ekeji Medadi : ẹmi na si bà lé wọn ;
nwọn si mbẹ ninu awọn ti a kà, ṣugbọn
nwọn kò jade lọ si agọ́, nwọn si nsọtẹlẹ ni
ibudó.
27 Ọmọkọnrin kan si súre, o si sọ fun
Mose, o si wipe, Eldadi ati Medadi nsọtẹlẹ
ni ibudó.
28 Joṣua ọmọ Nuni, iranṣẹ Mose, ọkan
ninu awọn ọmọkọnrin rẹ̀ dahùn, o si wipe,
Mose oluwa mi, dá wọn lẹkun.
29 Mose si wi fun u pe, Iwọ njowú ni-
tori mi ? gbogbo enia OLUWA iba le jẹ́ wolĩ,
ki OLUWA ki o fi ẹmi rẹ̀ si wọn lara !
30 Mose si lọ si ibudó, on ati awọn àgba
Israeli.
31 Afẹfẹ kan si ti ọdọ OLUWA jade lọ, o
si mú aparò lati okun wá, o si dà wọn si
ibudó, bi ìwọn ìrin ijọ́ kan ni ìha ihin, ati
bi ìwọn ìrin ijọ́ kan ni ìha ọhún yi ibudó
ká, ui ìwọn igbọnwọ meji lori ilẹ.
32 Awọn enia si duro ni gbogbo ọjọ́ na,
ati ni gbogbo oru na, ati ni gbogbo ọjọ́ keji,
nwọn si nkó aparò : ẹniti o kó kére, kó
òṣuwọn homeri mẹwa : nwọn si sá wọn
silẹ fun ara wọn yi ibudó ká.
33 Nigbati ẹran na si mbẹ lãrin ehín
wọn, ki nwọn ki o tó jẹ ẹ, ibinu OLUWA si
rú si awọn enia na, OLUWA si fi àrun nla
gidigidi kọlù awọn enia na.
34 A si pè orukọ ibẹ̀ na ni Kibrotu-hat-
taafa : nitoripe nibẹ̀ ni nwọn gbé sinku
awọn enia ti o ṣe ifẹkufẹ.
35 Awọn enia na si dide ìrin wọn lati
Kibrotu-hattaafa lọ si Haserotu ; nwọn si
dó si Haserotu.

## ORI 12.

ATI Miriamu ati Aaroni sọ̀rọ òdi si Mose
nitori obirin ara Etiopia ti o gbé ni
iyawo : nitoripe o gbé obirin ara Etiopia
kan ni iyawo.
2 Nwọn si wipe, Nipa Mose nikan ni
OLUWA ha sọ̀rọ bi ? kò ha ti ipa wa sọ̀rọ
pẹlu ? OLUWA si gbọ́ ọ.
3 Ṣugbọn ọkọnrin na Mose, o ṣe ọlọkàn
tutù jù gbogbo enia lọ ti mbẹ lori ilẹ.
4 OLUWA si sọ fun Mose, ati fun Aaroni

Digitized by Google

ati fun Miriamu li ojiji pe, Ẹnyin mẹtẹta ẹ
jade wá si agọ́ ajọ. Awọn mẹtẹta si jade.
5 OLUWA si sọkalẹ wá ninu ọwọ̀n awọ-
sanma, o si duro li ẹnu-ọ̀na agọ́ na, o si pè
Aaroni ati Miriamu: awọn mejeji si jade
wá.
6 O si wipe, Ẹ gbọ́ ọ̀rọ mi nisisiyi: bi
woli OLUWA ba mbẹ ninu nyin, emi OLU-
WA yio farahàn fun u li ojuran, emi o si bá
a sọ̀rọ li oju-alá.
7 Mose iranṣẹ mi kò ri bẽ, olõtọ ni ninu
gbogbo ile mi.
8 On li emi mbá sọ̀rọ li ẹnu ko ẹnu, ati
ni gbangba, ki si iṣe li ọ̀rọ ti o ṣe òkun-
kun; apẹrẹ OLUWA li on o si ri: njẹ nito-
ri kili ẹnyin kò ṣe bẹ̀ru lati sọ̀rọ òdi si
Mose iranṣẹ mi?
9 Ibinu OLUWA si rú si wọn; o si lọ.
10 Awọsanma si lọ kuro lori Agọ́ na; si
kiye si i, Miriamu di adẹtẹ̀, o fun bi òjo
didì; Aaroni si wò Miriamu, si kiyesi i, o
di adẹtẹ̀.
11 Aaroni si wi fun Mose pe, Yẽ, oluwa
mi, emi bẹ̀ ọ, maṣe kà ẹ̀ṣẹ na si wa lọrùn,
eyiti awa fi wère ṣe, ati eyiti awa ti dẹ̀ṣẹ.
12 Emi bẹ̀ ọ maṣe jẹ ki o dabi ẹniti o
kú, ẹniti àbọ ara rẹ̀ run tán nigbati o ti
inu iya rẹ̀ jade.
13 Mose si kigbe pè OLUWA, wipe, Ọlọ-
run, emi bẹ̀ ọ, mu u lara dá nisisiyi.
14 OLUWA si wi fun Mose pe, Bi baba
rẹ̀ tilẹ tu itọ si i li oju, njẹ oju ki ba ti i ni
ijọ́ meje? Ki a sé e mọ́ ẹhin ibudó ni
ijọ́ meje, lẹhin eyinì ki a gbà a sinu rẹ̀.
15 A si sé Miriamu mọ́ ẹhin ibudó ni
ijọ́ meje: awọn enia kò si ṣí titi a fi gbà
Miriamu pada.
16 Lẹhin eyinì li awọn enia si ṣí kuro
ni Haserotu, nwọn si dó si ijù Parani.

## ORI 13.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Rán enia, ki nwọn ki o si ṣe amí
ilẹ Kenaani, ti mo fi fun awọn ọmọ Israeli:
ọkọnrin kan ni ki ẹnyin ki o rán ninu ẹ̀ya
awọn baba wọn, ki olukuluku ki o jẹ́ ijoye
ninu wọn.
3 Mose si rán wọn lati ijù Parani lọ,
gẹgẹ bi aṣẹ OLUWA: gbogbo awọn ọkọnrin
na jẹ́ olori awọn ọmọ Israeli.
4 Orukọ wọn si ni wọnyi: ninu ẹ̀ya
Reubeni, Ṣammua ọmọ Sakuru.
5 Ninu ẹ̀ya Simeoni, Ṣafati ọmọ Hori.
6 Ninu ẹ̀ya Juda, Kalebu ọmọ Jefunne.
7 Ninu ẹ̀ya Issakari, Igali ọmọ Josefu.
8 Ninu ẹ̀ya Efraimu, Oṣea ọmọ Nuni.
9 Ninu ẹ̀ya Benjamini, Palti ọmọ Rafu.
10 Ninu ẹ̀ya Sebuluni, Gaddieli ọmọ
Sodi.
11 Ninu ẹ̀ya Josefu, eyinì ni, ninu ẹ̀ya
Manasse, Gadi ọmọ Susi.
12 Ninu ẹ̀ya Dani, Ammieli ọmọ Ge-
malli.
13 Ninu ẹ̀ya Aṣeri, Seturu ọmọ Mikaeli.
14 Ninu ẹ̀ya Naftali, Nabi ọmọ Fofsi.
15 Ninu ẹ̀ya Gaddi, Geueli ọmọ Maki.
16 Wọnyi li orukọ awọn ọkọnrin na, ti
Mose rán lati lọ ṣe amí ilẹ na. Mose si sọ
Oṣea ọmọ Nuni ni Joṣua.
17 Mose si rán wọn lọ ṣe amí ilẹ Kena-
ani, o si wi fun wọn pe, Ẹ gbà ọ̀na ìha
gusù yi, ki ẹ si lọ sori òke nì.
18 Ki ẹnyin si wò ilẹ na, bi o ti ri; ati
awọn enia ti ngbé inu rẹ̀, bi nwọn ṣe ala-
gbara tabi alailagbara, bi diẹ ni nwọn, tabi
pupọ̀;
19 Ati bi ilẹ na ti nwọn ngbé ti ri, bi
didara ni bi buburu ni; ati bi ilu ti nwọn
ngbé ti ri, bi ninu agọ́ ni, tabi ninu ilu
odi;
20 Ati bi ilẹ na ti ri, bi ẹlẹtu ni tabi bi
aṣalẹ̀, bi igi ba mbẹ ninu rẹ̀, tabi kò sí. Ki
ẹnyin ki o si mu ọkàn le, ki ẹnyin si mú
ninu eso ilẹ na wá. Njẹ ìgba na jẹ́ akokò
pipọn akọ́so àjara.
21 Bẹ̃ni nwọn gòke lọ, nwọn si ṣe amí
ilẹ na lati ijù Sini lọ dé Rehobu, ati lọ si
Hamati.
22 Nwọn si ti ìha gusù gòke lọ, nwọn si
dé Hebroni; nibiti Ahimani, Ṣeṣai, ati
Talmai, awọn ọmọ Anaki gbé wà. (A ti
tẹ̀ Hebroni dó li ọdún meje ṣaju Soani
ni Egipti.)
23 Nwọn si dé odò Eṣkolu, nwọn si rẹ́
ọwọ́ àjara kan, ti on ti ìdi eso-àjara kan
lati ibẹ̀ wá, awọn enia meji si fi ọpá rù u;
nwọn si mú ninu eso-pomegranate, ati ti
ọpọtọ́ wá.
24 Nwọn si sọ ibẹ̀ na ni odò Eṣkolu, ni-
tori ìdi-eso ti awọn ọmọ Israeli rẹ́ lati ibẹ̀
wá.
25 Nwọn si pada ni rirìn ilẹ na wò lẹhin
ogoji ọjọ́.
26 Nwọn si lọ nwọn tọ̀ Mose wá, ati
Aaroni, ati gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli,
ni ijù Parani, ni Kadeṣi; nwọn si mú ọ̀rọ
pada tọ̀ wọn wá, ati gbogbo ijọ, nwọn si fi
eso ilẹ na hàn wọn.
27 Nwọn si rò fun u, nwọn si wipe, Awa
dé ilẹ na nibiti iwọ gbé rán wa lọ, nitõtọ li
o nṣàn fun warà ati fun oyin; eyi si li eso
rẹ̀.

Digitized by Google

28 Ṣugbọn alagbara ni awọn enia ti ngbé inu ilẹ na, ilu olodi si ni ilu wọn, nwọn tobi gidigidi: ati pẹlupẹlu awa ri awọn ọmọ Anaki nibẹ̀.

29 Awọn ara Amaleki si ngbé ilẹ ìha gusù: ati awọn Hitti, ati awọn Jebusi, ati awọn Amori, ngbé ori-òke: awọn ara Kenaani si ngbé ẹba okun, ati ni àgbegbe Jordani.

30 Kalebu si pa awọn enia lẹnu mọ́ niwaju Mose, o si wipe, Ẹ jẹ ki a gòke lọ lẹ̃kan, ki a si gbà a; nitoripe awa le ṣẹ́ ẹ.

31 Ṣugbọn awọn ọkọnrin ti o bá a gòke lọ wipe, Awa kò le gòke tọ̀ awọn enia na lọ; nitoriti nwọn lagbara jù wa lọ.

32 Nwọn si mú ìhin buburu ti ilẹ na, ti nwọn ti ṣe amí wá fun awọn ọmọ Israeli, wipe, Ilẹ na ti awa là já lati ṣe amí rẹ̀, ilẹ ti imu awọn enia rẹ̀ jẹ ni; ati gbogbo enia ti awa ri ninu rẹ̀ jẹ́ enia ti o sigbọnlẹ.

33 Ati nibẹ̀ li awa gbé ri awọn omirán, awọn ọmọ Anaki ti o ti inu awọn omirán wá: awa si dabi ẹlẹnga li oju ara wa, bẹ̃li awa si ri li oju wọn.

## ORI 14.

GBOGBO ijọ si gbé ohùn wọn soke, nwọn si ke: awọn enia na si sọkun li oru na.

2 Gbogbo awọn ọmọ Israeli si nkùn si Mose ati si Aaroni: gbogbo ijọ si wi fun wọn pe, Awa iba kuku ti kú ni ilẹ Egipti! tabi awa iba kú li aginjù yi!

3 Nitori kini OLUWA ṣe mú wa wá si ilẹ yi, lati ti ipa idà ṣubu? Awọn aya wa, ati awọn ọmọ wa yio di ijẹ: kò ha san fun wa ki a pada lọ si Egipti?

4 Nwọn si wi fun ara wọn pe, Ẹ jẹ ki a yàn olori, ki a si pada lọ si Egipti.

5 Nigbana ni Mose ati Aaroni doju wọn bolẹ niwaju gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli.

6 Ati Joṣua ọmọ Nuni ati Kalebu ọmọ Jefunne, ti o wà ninu awọn ti o ṣe amí ilẹ na, fà aṣọ wọn ya:

7 Nwọn si sọ fun gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli, wipe, Ilẹ na ti awa là já lati ṣe amí rẹ̀, ilẹ na dara gidigidi.

8 Bi OLUWA ba fẹ́ wa, njẹ yio mú wa wọ̀ inu ilẹ na yi, yio si fi i fun wa; ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin.

9 Ṣugbọn ẹ máṣe ṣọ̀tẹ si OLUWA, bẹ̃ni ki ẹ máṣe bẹ̀ru awọn enia ilẹ na; nitoripe onjẹ wa ni nwọn; àbo wọn ti fi wọn silẹ, OLUWA si wà pẹlu wa: ẹ máṣe bẹ̀ru wọn.

10 Gbogbo ijọ si wipe ki a sọ wọn li okuta. Ṣugbọn ogo OLUWA hàn ninu agọ́ ajọ niwaju gbogbo awọn ọmọ Israeli.

11 OLUWA si wi fun Mose pe, Awọn enia yi yio ti kẹgàn mi pẹ tó? yio si ti pẹ tó ti nwọn o ṣe alaigbà mi gbọ́, ni gbogbo iṣẹ-àmi ti mo ṣe lãrin wọn?

12 Emi o fi ajakalẹ-àrun kọlù wọn, emi o si gbà ogún wọn lọwọ wọn, emi o si sọ iwọ di orilẹ-ède nla, ati alagbara jù wọn lọ.

13 Mose si wi fun OLUWA pe, Ṣugbọn awọn ara Egipti yio gbọ́; nitoripe nipa agbara rẹ ni iwọ fi mú awọn enia yi jade lati inu wọn wá;

14 Nwọn o si wi fun awọn ara ilẹ yi: nwọn sá ti gbọ́ pe iwọ OLUWA mbẹ lãrin awọn enia yi, nitoripe a ri iwọ OLUWA li ojukoju, ati pe awọsanma rẹ duro lori wọn, ati pe iwọ li o ṣaju wọn, ninu ọwọ̀n awọsanma nigba ọsán, ati ninu ọwọ̀n iná li oru.

15 Njẹ bi iwọ ba pa gbogbo awọn enia yi bi ẹnikan, nigbana li awọn orilẹ-ède ti o ti gbọ́ okikí rẹ yio wipe,

16 Nitoriti OLUWA kò le mú awọn enia yi dé ilẹ ti o ti fi bura fun wọn, nitorina li o ṣe pa wọn li aginjù.

17 Njẹ nisisiyi, emi bẹ̀ ọ, jẹ ki agbara OLUWA ki o tobi, gẹgẹ bi iwọ ti sọ rí pe,

18 Olupamọra ati ẹniti o pọ̀ li ãnu li OLUWA, ti ndari ẹ̀ṣẹ ati irekọja jì, ati bi o ti wù ki o ri, ti ki ijẹ ki ẹlẹbi lọ laijìya; a ma bẹ̀ ẹ̀ṣẹ awọn baba wò lara awọn ọmọ, titi dé iran kẹta ati ẹkẹrin.

19 Emi bẹ̀ ọ, dari ẹ̀ṣẹ awọn enia yi jì, gẹgẹ bi titobi ãnu rẹ, ati bi iwọ ti darijì awọn enia yi, lati Egipti titi di isisiyi.

20 OLUWA si wipe, Emi ti darijì gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ:

21 Ṣugbọn nitõtọ, bi mo ti wà, gbogbo aiye yio si kún fun ogo OLUWA;

22 Nitori gbogbo awọn enia wọnyi ti o ti ri ogo mi, ati iṣẹ-àmi mi, ti mo ti ṣe ni Egipti ati li aginjù, ti nwọn si dan mi wò nigba mẹwa yi, ti nwọn kò si fetisi ohùn mi;

23 Nitõtọ nwọn ki yio ri ilẹ na ti mo ti fi bura fun awọn baba wọn, bẹ̃ni ọkan ninu awọn ti o gàn mi ki yio ri i:

24 Ṣugbọn Kalebu iranṣẹ mi, nitoriti o ní ọkàn miran ninu rẹ̀, ti o si tẹle mi mọtimọti, on li emi o múlọ sinu ilẹ na nibiti o ti rè; irú-ọmọ rẹ̀ ni yio si ní i.

25 Njẹ awọn ara Amaleki ati awọn ara Kenaani ngbé afonifoji: li ọla ẹ pada, ki ẹ si lọ si aginjù nipa ọ̀na Okun Pupa.

26 OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni pe,

27 Emi o ti mu sũru pẹ tó fun ijọ enia



Digitized by Google

buburu yi ti nkùn si mi ? Emi ti gbọ́ kikùn
awọn ọmọ Israeli, ti nwọn kùn si mi.
28 Wi fun wọn pe, OLUWA wipe, Bi
mo ti wà nitõtọ, bi ẹnyin ti sọ li etí mi,
bẽli emi o ṣe si nyin:
29 Okú nyin yio ṣubu li aginjù yi; ati
gbogbo awọn ti a kà ninu nyin, gẹgẹ bi iye
gbogbo nyin, lati ẹni ogún ọdún lọ ati jú
bẽ lọ, ti ẹ kùn si mi,
30 Ẹnyin ki yio dé inu ilẹ na, ti mo ti
bura lati mu nyin gbé inu rẹ̀, bikoṣe Kalebu
ọmọ Jefunne, ati Joṣua ọmọ Nuni.
31 Ṣugbọn awọn ọmọ wẹ́wẹ nyin, ti
ẹnyin wipe yio di ijẹ, awọn li emi o muwọ̀
ọ, awọn ni yio si mọ̀ ilẹ na ti ẹnyin gàn.
32 Ṣugbọn ẹnyin, okú nyin yio ṣubu li
aginjù yi.
33 Awọn ọmọ nyin yio si ma rìn kiri li
aginjù li ogoji ọdún, nwọn o si ma rù ìwa-
àgbere nyin, titi okú nyin yio fi ṣòfo tán li
aginjù.
34 Gẹgẹ bi iye ọjọ́ ti ẹnyin fi rìn ilẹ na
wò, ani ogoji ọjọ́, ọjọ́ kan fun ọdún kan, li
ẹnyin o rù ẹ̀ṣẹ nyin, ani ogoji ọdún, ẹnyin
o si mọ̀ ibà ileri mi jẹ́.
35 Emi OLUWA ti sọ, Emi o ṣe e nitõtọ
si gbogbo ijọ buburu yi, ti nwọn kójọ pọ̀ si
mi: li aginjù yi ni nwọn o run, nibẹ̀ ni
nwọn o si kú si.
36 Ati awọn ọkọnrin na ti Mose rán lọ
lati rìn ilẹ na wò, ti nwọn pada, ti nwọn
si mu gbogbọ ijọ kùn si i, ni mimú ìhin
buburu ilẹ na wá,
37 Ani awọn ọkọnrin na ti o mú ìhin
buburu ilẹ na wá, nwọn ti ipa àrun kú
niwaju OLUWA.
38 Ṣugbọn Joṣua ọmọ Nuni, ati Kalebu
ọmọ Jefunne, ninu awọn ọkọnrin na ti o
rìn ilẹ na lọ, wà lãye.
39 Mose si sọ ọ̀rọ wọnyi fun gbogbo
awọn ọmọ Israeli: awọn enia na si kãnu
gidigidi.
40 Nwọn si dide ni kùtukutu owurọ̀,
nwọn si gùn ori òke nì lọ, wipe, Kiyesi i,
awa niyi, awa o si gòke lọ si ibiti OLUWA
ti ṣe ileri: nitoripe awa ti ṣẹ̀.
41 Mose si wipe, Ẽṣe ti ẹnyin fi nré aṣẹ
OLUWA kọja ? ki yio sa gbè nyin.
42 Ẹ máṣe gòke lọ, nitoriti OLUWA kò
sí lãrin nyin, ki a má ba lù nyin bolẹ
niwaju awọn ọtá nyin.
43 Nitoriti awọn ara Amaleki ati awọn
ara Kenaani mbẹ niwaju nyin, ẹnyin o si ti
ipa idà ṣubu: nitoriti ẹnyin ti yipada kuro
lẹhin OLUWA, nitorina OLUWA ki yio si
pẹlu nyin.
44 Ṣugbọn nwọn fi igberaga gòke lọ sori
òke na: ṣugbọn apoti ẹrí OLUWA, ati Mose,
kò jade kuro ni ibudò.
45 Nigbana li awọn ara Amaleki sọkalẹ
wá, ati awọn ara Kenaani ti ngbé ori-òke
na, nwọn si kọlù wọn, nwọn si ṣẹ́ wọn titi
dé Horma.

## ORI 15.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba dé ilẹ ibu-
joko nyin, ti mo fi fun nyin,
3 Ti ẹnyin o ba si ṣe ẹbọ iná si OLUWA,
ẹbọ sisun, tabi ẹbọ, lati san ẹjẹ́, tabi ẹbọ
ifẹ́-atinuwá, tabi ninu ajọ nyin lati ṣe õrùn
didùn si OLUWA ninu agbo-ẹran, tabi ọwọ́-
ẹran:
4 Nigbana ni ki ẹniti nru ọrẹ-ẹbọ rẹ̀ na
si OLUWA ki o mú ẹbọ ohunjijẹ wá, idamẹ-
wa òṣuwọn iyẹfun ti a fi idamẹrin òṣuwọn
hini oróro pò:
5 Ati idamẹrin òṣuwọn hini ọti-waini
fun ẹbọ ohunmimu ni ki iwọ ki o pèse pẹlu
ẹbọ sisun, tabi ẹbọ, fun ọdọ-agutan kan.
6 Tabi fun àgbo kan, ki iwọ ki o pèse
ẹbọ ohunjijẹ idamẹwa meji òṣuwọn iyẹfun
pẹlu idamẹta òṣuwọn hini oróro:
7 Ati fun ẹbọ ohunmimu, ki iwọ ki o
mú idamẹta òṣuwọn hini ọti-waini wá, fun
õrùn didùn si OLUWA.
8 Bi iwọ ba si pèse ẹgbọrọ akọmalu kan
fun ẹbọ sisun, tabi fun ẹbọ kan, lati san
ẹjẹ́, tabi ẹbọ alafia si OLUWA:
9 Nigbana ni ki o mu wá pẹlu ẹgbọrọ
akọmalu na, ẹbọ ohunjijẹ idamẹwa mẹta
òṣuwọn iyẹfun ti a fi àbọ òṣuwọn hini oróro
pò.
10 Ki iwọ ki o si múwa fun ẹbọ ohunmi-
mu àbọ òṣuwọn hini ọti-waini, ẹbọ ti a fi
iná ṣe, õrùn didùn si OLUWA.
11 Bayi ni ki a ṣe niti akọmalu kan, tabi
niti àgbo kan, tabi niti akọ ọdọ-agutan kan,
tabi niti ọmọ-ewurẹ kan.
12 Gẹgẹ bi iye ti ẹnyin o pèse, bẽni ki
ẹnyin ki o ṣe si olukuluku gẹgẹ bi iye
wọn.
13 Gbogbo ibilẹ ni ki o ma ṣe nkan
wọnyi bayi, nigbati nwọn ba nru ẹbọ ti a
fi iná ṣe, ti õrùn didùn si OLUWA.
14 Ati bi alejò kan ba nṣe atipo lọdọ
nyin, tabi ẹnikẹni ti o wù ki o ṣe ninu nyin
ni iran nyin, ti o si nfẹ́ ru ẹbọ ti a fi iná
ṣe, ti õrùn didùn si OLWA; bi ẹnyin ti ṣe,
bẽni ki on ki o ṣe.
15 Ìlana kan ni ki o wà fun ẹnyin ijọ

Digitized by Google

enia, ati fun alejò ti nṣe atipo lọdọ nyin, ìlana titilai, ni iran-iran nyin: bi ẹnyin ti ri, bẹ̃ni ki alejò ki o si ri niwaju OLUWA.
16 Ofin kan ati ìlana kan ni ki o wà fun nyin, ati fun alejò ti nṣe atipo lọdọ nyin.
17 OLUWA si sọ fun Mose pe,
18 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba dé ilẹ na nibiti emi nmú nyin lọ,
19 Yio si ṣe, nigbati ẹnyin ba njẹ ninu onjẹ ilẹ na, ki ẹnyin ki o mú ẹbọ igbesọsoke wá fun OLUWA.
20 Ki ẹnyin ki o mú àkara atetekọṣu iyẹfun nyin wá fun ẹbọ igbesọsoke: bi ẹnyin ti ṣe ti ẹbọ igbesọsoke ilẹ ipakà, bẹ̃ni ki ẹnyin gbé e sọ.
21 Ninu atetekọ́ṣu iyẹfun nyin ni ki ẹnyin ki o fi fun OLUWA li ẹbọ igbesọsoke, ni iran-iran nyin.
22 Bi ẹnyin ba si ṣìṣe, ti ẹnyin kò si kiyesi gbogbo ofin wọnyi ti OLUWA ti sọ fun Mose,
23 Ani gbogbo eyiti OLUWA ti paṣẹ fun nyin lati ọwọ́ Mose wá, lati ọjọ́ na ti OLUWA ti paṣẹ fun Mose, ati lati isisiyi lọ, ni iran-iran nyin;
24 Yio si ṣe, bi a ba fi aimọ̀ ṣe ohun kan ti ijọ kò mọ̀, ki gbogbo ijọ ki o mú ẹgbọrọ akọmalu kan wá fun ẹbọ sisun, fun õrùn didùn si OLUWA, pẹlu ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ ohunmimu rẹ̀, gẹgẹ bi ìlana na, ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ.
25 Ki alufa ki o si ṣètutu fun gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli, a o si dariji wọn; nitoripe aimọ̀ ni, nwọn si ti mú ọrẹ-ẹbọ wọn wá, ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA, ati ẹbọ ẹ̀ṣẹ wọn niwaju OLUWA, nitori aimọ̀ wọn:
26 A o si dariji gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli, ati alejò ti iṣe atipo lọdọ wọn; nitoripe gbogbo enia wà li aimọ̀.
27 Bi ọkàn kan ba si fi aimọ̀ ṣẹ̀, nigbana ni ki o mú abo-ewurẹ ọlọdún kan wá, fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ.
28 Ki alufa ki o ṣètutu fun ọkàn na ti o ṣẹ̀, nigbati o ba ṣẹ̀ li aimọ̀ niwaju OLUWA, lati ṣètutu fun u; a o si dariji i.
29 Ofin kan ni ki ẹnyin ki o ni fun ẹniti o ṣẹ̀ li aimọ̀, ati fun ẹniti a bi ninu awọn ọmọ Israeli, ati fun alejò ti nṣe atipo ninu wọn.
30 Ṣugbọn ọkàn na ti o ba fi ikugbu ṣe ohun kan, iba ṣe ibilẹ tabi alejò, o sọ̀rọ buburu si OLUWA; ọkàn na li a o si ke kuro ninu awọn enia rẹ̀.
31 Nitoriti o gàn ọ̀rọ OLUWA, o si ru ofin rẹ̀; ọkàn na li a o ke kuro patapata, ẹ̀ṣẹ rẹ̀ yio wà lori rẹ̀.
32 Nigbati awọn ọmọ Israeli wà li aginjù, nwọn ri ọkọnrin kan ti nṣẹ́ igi li ọjọ́isimi.
33 Awọn ti o ri i ti nṣẹ́ igi mú u tọ̀ Mose ati Aaroni wá, ati gbogbo ijọ.
34 Nwọn si há a mọ́ ile-ìde, nitoriti a kò ti isọ bi a o ti ṣe e.
35 OLUWA si sọ fun Mose pe, Pipa li a o pa ọkọnrin na: gbogbo ijọ ni yio sọ ọ li okuta pa lẹhin ibudó.
36 Gbogbo ijọ si mú u wá sẹhin ibudó, nwọn si sọ ọ li okuta, on si kú; bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose.
37 OLUWA si sọ fun Mose pe,
38 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si fi aṣẹ fun wọn ki nwọn ki o ṣe wajawaja si eti aṣọ wọn ni iran-iran wọn, ati ki nwọn ki o si fi ọjábulẹ aláró si wajawaja eti aṣọ na:
39 Yio si ma ṣe bi wajawaja fun nyin, ki ẹnyin ki o le ma wò o, ki ẹ si ma ranti gbogbo ofin OLUWA, ki ẹ si ma ṣe wọn: ki ẹnyin ki o má si ṣe tẹle ìro ọkàn nyin ati oju ara nyin, ti ẹnyin ti ima ṣe àgbere tọ̀lẹhin:
40 Ki ẹnyin ki o le ma ranti, ki ẹ si ma ṣe ofin mi gbogbo, ki ẹnyin ki o le jẹ́ mimọ́ si Ọlọrun nyin.
41 Emi ni OLUWA Ọlọrun nyin, ti o mú nyin jade lati ilẹ Egipti wá, lati ma ṣe Ọlọrun nyin: Emi ni OLUWA Ọlọrun nyin.

## ORI 16.

NJẸ Kora, ọmọ Ishari, ọmọ Kohati, ọmọ Lefi, ati Datani on Abiramu, awọn ọmọ Eliabu, ati On, ọmọ Peleti, awọn ọmọ Reubeni, dìmọ:
2 Nwọn si dide niwaju Mose, pẹlu ãdọtalerugba ọkọnrin ninu awọn ọmọ Israeli, ijoye ninu ijọ, awọn oloruko ninu ajọ, awọn ọkọnrin olokiki:
3 Nwọn si kó ara wọn jọ pọ̀ si Mose ati si Aaroni, nwọn si wi fun wọn pe, O tó gẹ, nitoripe gbogbo ijọ li o jẹ́ mimọ́, olukuluku wọn, OLUWA si mbẹ lãrin wọn: nitori kili ẹnyin ha ṣe ngbé ara nyin ga jù ijọ OLUWA lọ?
4 Nigbati Mose gbọ́, o doju rẹ̀ bolẹ:
5 O si sọ fun Kora ati fun gbogbo ẹgbẹ rẹ̀ pe, Li ọla OLUWA yio fi ẹniti iṣe tirẹ̀ hàn, ati ẹniti o mọ́; yio si mu u sunmọ ọdọ rẹ̀: ani ẹniti on ba yàn ni yio mu sunmọ ọdọ rẹ̀.

Digitized by Google

6 Ẹ ṣe eyi; Ẹ mú awo-turari, Kora, ati
gbogbo ẹgbẹ rẹ̀;
7 Ki ẹ si fi iná sinu wọn, ki ẹ si fi turari
sinu wọn niwaju OLUWA li ọla: yio si ṣe,
ọkọnrin ti OLUWA ba yàn, on ni ẹni mimọ́:
o tó gẹ, ẹnyin ọmọ Lefi.
8 Mose si wi fun Kora pe, Emi bẹ̀ nyin,
ẹnyin ọmọ Lefi, ẹ gbọ́:
9 Ohun kekere ha ni li oju nyin, ti Ọlọ-
run Israeli yà nyin kuro ninu ijọ Israeli,
lati mú nyin sunmọ ọdọ ara rẹ̀ lati ma ṣe
iṣẹ-ìsin agọ́ OLUWA, ati lati ma duro ni-
waju ijọ lati ma ṣe iranṣẹ fun wọn;
10 O si mú iwọ sunmọ ọdọ rẹ̀, ati awọn
arakọnrin rẹ gbogbo, awọn ọmọ-Lefi pẹlu
rẹ; ẹnyin si nwá iṣẹ-alufa pẹlu?
11 Nitorina, iwọ ati gbogbo ẹgbẹ rẹ kó-
jọ pọ̀ si OLUWA: ati kini Aaroni, ti ẹnyin
nkùn si i?
12 Mose si ranṣẹ pè Datani ati Abiramu,
awọn ọmọ Eliabu: nwọn si wipe, Awa ki
yio gòke wá:
13 Ohun kekere ha ni ti iwọ mú wa gòke
lati ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin wá,
lati pa wa li aginjù, ti iwọ fi ara rẹ jẹ́ alade
lori wa patapata?
14 Pẹlupẹlu iwọ kò ti imú wa dé ilẹ kan
ti nṣàn fun warà ati fun oyin, bẹ̃ni iwọ kò
fun wa ni iní ilẹ ati ọgba-àjara: iwọ o yọ
oju awọn ọkọnrin wọnyi bi? awa ki yio
gòke wá.
15 Mose si binu gidigidi, o si wi fun
OLUWA pe, Máṣe kà ẹbọ wọn si: emi kò
gbà kẹtẹkẹtẹ kan lọwọ wọn, bẹ̃li emi kò pa
ẹnikan wọn lara.
16 Mose wi fun Kora pe, Ki iwọ ati gbo-
gbo ẹgbẹ rẹ ki o wá siwaju OLUWA, iwọ,
ati awọn ati Aaroni li ọla:
17 Ki olukuluku wọn ki o mú awo-tura-
ri rẹ̀, ki ẹ si fi turari sinu wọn, ki olukulu-
ku nyin ki o mú awo-turari rẹ̀ wá siwaju
OLUWA, ãdọtalerugba awo-turari; iwọ pẹlu
ati Aaroni, olukuluku awo-turari rẹ̀.
18 Olukuluku wọn si mú awo-turari rẹ̀,
nwọn si fi iná sinu wọn, nwọn si fi turari
lé ori wọn, nwọn si duro li ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ,
pẹlu Mose ati Aaroni.
19 Kora si kó gbogbo ijọ enia jọ si wọn
si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ: ogo OLUWA si hàn si
gbogbo ijọ enia na.
20 OLUWA si sọ fun Mose ati Aaroni
pe,
21 Ẹ yà ara nyin kuro lãrin ijọ yi, ki
emi ki o run wọn ni iṣẹju kan.
22 Nwọn si doju wọn bolẹ, nwọn wipe,
Ọlọrun, Ọlọrun ẹmi gbogbo enia, ọkọnrin
kan ha le ṣẹ̀, ki iwọ ki o si binu si gbogbo
ijọ?
23 OLUWA si sọ fun Mose pe,
24 Sọ fun ijọ pe, Ẹ gòke wá kuro ni sa-
kani agọ́ Kora, Datani, ati Abiramu.
25 Mose si dide, o si tọ̀ Datani ati Abi-
ramu lọ; awọn àgba Israeli si tẹle e.
26 O si sọ fun ijọ pe, Mo bẹ̀ nyin, ẹ
kuro ni ibi agọ́ awọn ọkọnrin buburu yi, ẹ
má si ṣe fọwọkàn ohun kan ti iṣe ti wọn,
ki ẹ má ba run ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ wọn.
27 Bẹ̃ni nwọn si gòke lọ kuro nibi agọ́
Kora, Datani ati Abiramu, ni ìha gbogbo:
Datani ati Abiramu si jade, nwọn si duro li
ẹnu-ọ̀na agọ́ wọn, ati awọn aya wọn, ati
awọn ọmọ wọn ọkọnrin, ati awọn ọmọ wọn
wẹ́wẹ.
28 Mose si wipe, Nipa eyi li ẹnyin o mọ̀
pe OLUWA li o rán mi lati ṣe gbogbo iṣẹ
wọnyi; ati pe emi kò ṣe wọn lati inu ara
mi wá.
29 Bi awọn ọkọnrin wọnyi ba kú bi
gbogbo enia ti ikú, tabi bi a ba si bẹ̀ wọn
wò bi ãti ibẹ̀ gbogbo enia wọ̀; njẹ OLUWA
kọ́ rán mi.
30 Ṣugbọn bi OLUWA ba ṣe ohun titun,
ti ilẹ ba si là ẹnu rẹ̀, ti o si gbe wọn mì,
pẹlu ohun gbogbo ti iṣe ti wọn, ti nwọn si
sọkalẹ lọ si ipò-okú lãye; nigbana ẹnyin o
mọ̀ pe awọn ọkọnrin wọnyi ti gàn OLUWA.
31 O si ṣe, bi o ti pari gbogbo ọ̀rọ wọnyi
ni sisọ, ni ilẹ là pẹrẹ nisalẹ wọn:
32 Ilẹ si yà ẹnu rẹ̀, o si gbe wọn mì, ati
awọn ara ile wọn, ati gbogbo awọn enia ti
iṣe ti Kora, ati gbogbo ẹrù wọn.
33 Awọn, ati ohun gbogbo ti iṣe ti wọn,
sọkalẹ lọ lãye si ipò-okú, ilẹ si pa ẹnu dé
mọ́ wọn, nwọn si run kuro ninu ijọ.
34 Gbogbo enia Israeli ti o yi wọn ká si
salọ nitori igbe wọn: nitoriti nwọn wipe,
Ki ilẹ ki o má ba gbe wa mì pẹlu,
35 Iná si jade wá lati ọdọ OLUWA, o si
run awọn ãdọtalerugba ọkọnrin nì ti nwọn
mú turari wá.
36 OLUWA si sọ fun Mose pe,
37 Sọ fun Eleasari ọmọ Aaroni alufa, pe
ki o mú awo-turari wọnni kuro ninu ijóna,
ki iwọ ki o si tu iná na ká sọhún; nitoripe
nwọn jẹ́ mimọ́.
38 Awo-turari ti awọn ẹlẹṣẹ wọnyi si
ọkàn ara wọn, ni ki nwọn ki o fi ṣe awo
fẹlẹfẹlẹ fun ibori pẹpẹ: nitoriti nwọn mú
wọn wá siwaju OLUWA, nitorina ni nwọn
ṣe jẹ́ mimọ́: nwọn o si ma ṣe àmi fun awọn
ọmọ Israeli.
39 Eleasari alufa si mú awo-turari idẹ

Digitized by Google

wọnni, eyiti awọn ẹniti o jóna fi mú ẹbọ
wá; a si rọ wọn li awo fẹlẹfẹlẹ fun ibori
pẹpẹ:
40 Lati ma ṣe ohun iranti fun awọn ọmọ
Israeli, ki alejò kan, ti ki iṣe irú-ọmọ
Aaroni, ki o máṣe sunmọtosi lati mú turari
wá siwaju OLUWA; ki o má ba dabi Kora,
ati awọn ẹgbẹ rẹ̀: bi OLUWA ti wi fun u
lati ọwọ́ Mose wá.
41 Ṣugbọn ni ijọ́ keji gbogbo ijọ awọn
ọmọ Israeli nkùn si Mose ati si Aaroni,
wipe, Ẹnyin pa awọn enia OLUWA.
42 O si ṣe, nigbati ijọ pejọ pọ̀ si Mose
ati si Aaroni, ti nwọn si wò iha agọ́ ajọ: si
kiyesi i, awọsanma bò o, ogo OLUWA si
farahàn.
43 Mose ati Aaroni si wá siwaju agọ́ ajọ.
44 OLUWA si sọ fun Mose pe,
45 Ẹ lọ kuro lãrin ijọ yi, ki emi ki o
run wọn ni iṣẹju kan. Nwọn si doju wọn
bolẹ.
46 Mose si wi fun Aaroni pe, Mú awo-
turari kan, ki o si fi iná sinu rẹ̀ lati ori
pẹpẹ nì wá, ki o si fi turari lé ori rẹ̀, ki o
si yará lọ sọdọ ijọ, ki o si ṣètutu fun wọn:
nitoriti ibinu jade lati ọdọ OLUWA lọ; iyọ-
nu ti bẹ̀rẹ na.
47 Aaroni si mú awo-turari bi Mose ti fi
aṣẹ fun u, o si sure lọ sãrin ijọ; si kiyesi
i, iyọnu ti bẹ̀rẹ na lãrin awọn enia: o
si fi turari sinu rẹ̀, o si ṣètutu fun awọn
enia na.
48 O si duro li agbedemeji okú ati alãye;
iyọnu na si duro.
49 Awọn ti o kú ninu iyọnu na si jẹ́
ẹgba meje o le ẽdẹgbẹrin, laika awọn ti o
kú niti ọran Kora.
50 Aaroni si pada tọ̀ Mose lọ si ibi ẹnu-
ọ̀na agọ́ ajọ: iyọnu na si duro.

ORI 17.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si gbà
ọpá kọkan lọwọ wọn, gẹgẹ bi ile awọn ba-
ba won, lọwọ gbogbo awọn olori wọn gẹgẹ
bi ile awọn baba wọn, ọpá mejila: ki o si
kọ orukọ olukuluku si ara ọpá rẹ̀.
3 Ki o si kọ orukọ Aaroni sara ọpá Lefi:
nitoripe ọpá kan yio jẹ́ fun ori ile awọn
baba wọn.
4 Ki o si fi wọn lelẹ ninu agọ́ ajọ, niwa-
ju ẹrí, nibiti emi o gbé pade nyin.
5 Yio si ṣe, ọpá ẹniti emi o yàn yio ru-
we: emi o si da kikùn awọn ọmọ Israeli
duro kuro lọdọ mi, ti nwọn nkùn si nyin.
6 Mose si sọ fun awọn ọmọ Israeli, gbo-
gbo awọn olori wọn si fun u li ọpá, ọpá
kan fun olori kan, gẹgẹ bi ile awọn baba
wọn, ani ọpá mejila: ọpá Aaroni si wà ni-
nu ọpá wọn.
7 Mose si fi ọpá wọnni lelẹ niwaju OLU-
WA ninu agọ́ ẹrí.
8 O si ṣe, ni ijọ́ keji ti Mose wọ̀ inu agọ́
ẹrí lọ; si kiyesi i, ọpá Aaroni fun ile Lefi
rudi, o si tú, o si tanna, o si so eso almondi.
9 Mose si kó gbogbo ọpá na lati iwaju
OLUWA jade tọ̀ gbogbo awọn ọmọ Israeli
wá: nwọn si wò, olukuluku si mú ọpá tirẹ̀.
10 OLUWA si sọ fun Mose pe, Mú ọpá
Aaroni pada wa siwaju ẹrí, lati fi pamọ́ fun
àmi fun awọn ọlọ̀tẹ nì; ki iwọ ki o si gbà
kikùn wọn kuro lọdọ mi patapata ki nwọn
ki o má ba kú.
11 Mose si ṣe bẹ̃: bi OLUWA ti fi aṣẹ
fun u, bẹ̃li o ṣe.
12 Awọn ọmọ Israeli si sọ fun Mose pe,
Kiyesi i, awa kú, awa gbé, gbogbo wa gbé.
13 Ẹnikẹni ti o ba sunmọ agọ́ OLUWA
yio kú: awa o ha fi kikú run bi?

ORI 18.

OLUWA si sọ fun Aaroni pe, Iwọ ati
awọn ọmọ rẹ, ati ile baba rẹ pẹlu rẹ,
ni yio ma rù ẹ̀ṣẹ ibi-mimọ́: ati iwọ ati
awọn ọmọ rẹ pẹlu rẹ ni yio ma rù ẹ̀ṣẹ iṣẹ-
alufa nyin.
2 Ati awọn arakọnrin rẹ pẹlu, ẹ̀ya Lefi,
ẹ̀ya baba rẹ, ni ki o múwa pẹlu rẹ, ki nwọn
ki o le dàpọ pẹlu rẹ, ki nwọn ki o ma ṣe
iranṣẹ fun ọ: ṣugbọn iwọ ati awọn ọmọ rẹ
pẹlu rẹ ni yio ma ṣe iranṣẹ niwaju agọ́ ẹrí.
3 Ki nwọn ki o ma pa aṣẹ rẹ mọ́, ki
nwọn ki o si ma ṣe itọju gbogbo agọ́, kìki
pe nwọn kò gbọdọ sunmọ ohun-èlo ibi-mimọ́
ati pẹpẹ, ki ati awọn, ati ẹnyin pẹlu ki o
má ba kú.
4 Ki nwọn ki o si dàpọ pẹlu rẹ, ki nwọn
ki o si ma ṣe itọju agọ́ ajọ, gẹgẹ bi gbogbo
iṣẹ-ìsin agọ́: alejò kan kò si gbọdọ sunmọ
ọdọ nyin.
5 Ki ẹnyin ki o si ma ṣe itọju ibi-mimọ́,
ati itọju pẹpẹ: ki ibinu ki o má ba si mọ́
lori awọn ọmọ Israeli.
6 Ati emi, kiyesi i, mo ti mú awọn ara-
kọnrin nyin, awọn ọmọ Lefi kuro ninu
awọn ọmọ Israeli: ẹnyin li a fi wọn fun bi
ẹ̀bun fun OLUWA, lati ma ṣe iṣẹ-ìsin agọ́
ajọ.
7 Iwọ ati awọn ọmọ rẹ pẹlu rẹ ni yio si
ma ṣe itọju iṣẹ-alufa nyin niti ohun gbogbo
ti iṣe ti pẹpẹ, ati ti inu aṣọ-ikele: ẹnyin o
si ma sìn: emi ti fi iṣẹ-alufa nyin fun nyin,

Digitized by Google

bi iṣẹ-ìsin ẹ̀bun: alejò ti o ba si sunmọtosi
li a o pa.
8 Oluwa si sọ fun Aaroni pe, Kiyesi i,
emi si ti fi itọju ẹbọ igbesọsoke mi fun ọ
pẹlu, ani gbogbo ohun mimọ́ awọn ọmọ
Israeli, iwọ li emi fi wọn fun ni ipín, ati
fun awọn ọmọ rẹ, bi ipín lailai.
9 Eyi ni yio ṣe tirẹ ninu ohun mimọ́
julọ, ti a mú kuro ninu iná; gbogbo ọrẹ-
ẹbọ wọn, gbogbo ẹbọ ohunjijẹ won, ati
gbogbo ẹbọ ẹ̀ṣẹ wọn, ati gbogbo ẹbọ ẹbi
wọn, ti nwọn o mú fun mi wá, mimọ́ julọ
ni yio jasi fun iwọ ati fun awọn ọmọ rẹ.
10 Bi ohun mimọ́ julọ ni ki iwọ ki o ma
jẹ ẹ: gbogbo ọkọnrin ni yio jẹ ẹ; mimọ́ ni
yio jẹ́ fun ọ.
11 Eyi si ni tirẹ; ẹbọ igbesọsoke ẹ̀bun
wọn, pẹlu gbogbo ẹbọ fifì awọn ọmọ Israeli:
emi ti fi wọn fun ọ, ati fun awọn ọmọ rẹ
ọkọnrin ati fun awọn ọmọ rẹ obirin pẹlu
rẹ, bi ipín lailai: gbogbo awọn ti o mọ́ ni-
nu ile rẹ ni ki o jẹ ẹ.
12 Gbogbo oróro daradara, ati gbogbo
ọti-waini daradara, ati alikama, akọ́so ninu
wọn ti nwọn o mú fun Oluwa wá, iwọ ni
mo fi wọn fun.
13 Akọ́so gbogbo ohun ti o wà ni ilẹ
wọn, ti nwọn o mú fun Oluwa wá, tirẹ ni
yio jẹ́; gbogbo ẹniti o mọ́ ni ile rẹ ni ki o
jẹ ẹ.
14 Ohun ìyasọtọ gbogbo ni Israeli ni ki
o jẹ́ tirẹ.
15 Gbogbo akọ́bi ninu gbogbo ohun
alãye, ti nwọn o múwa fun Oluwa, iba ṣe
ti enia tabi ti ẹranko, ki o jẹ́ tirẹ: ṣugbọn
rirà ni iwọ o rà akọ́bi enia silẹ, ati akọ́bi
ẹran alaimọ́ ni ki iwọ ki o rà silẹ.
16 Gbogbo awọn ti a o ràsilẹ, lati ẹni
oṣù kan ni ki iwọ ki o ràsilẹ, gẹgẹ bi idi-
yelé rẹ, li owo ṣekeli marun, nipa ṣekeli
ibi-mimọ́ (ti o jẹ́ ogun gera).
17 Ṣugbọn akọ́bi akọmalu, tabi akọbi
agutan, tabi akọ́bi ewurẹ, ni iwọ kò gbọdọ
ràsilẹ; mimọ́ ni nwọn: ẹ̀jẹ wọn ni ki iwọ
ki o ta sori pẹpẹ, ki iwọ ki o si sun ọrá
wọn li ẹbọ ti a fi iná ṣe, fun õrùn didùn si
Oluwa.
18 Ki ẹran wọn ki o si jẹ́ tirẹ, bi àiya
fifì, ati bi itan ọtún, ni yio jẹ́ tirẹ.
19 Gbogbo ẹbọ igbesọsoke ohun mimọ́
wọnni, ti awọn ọmọ Israeli múwa fun
Oluwa, ni mo ti fi fun ọ, ati fun awọn
ọmọ rẹ ọkọnrin, ati fun awọn ọmọ rẹ obirin
pẹlu rẹ, bi ipín lailai: majẹmu iyọ̀ ni lai-
lai niwaju Oluwa fun ọ ati fun irú-ọmọ rẹ
pẹlu rẹ.
20 Oluwa si sọ fun Aaroni pe, Iwọ ki
yio ní iní ninu ilẹ wọn, bẹ̃ni iwọ ki yio ní
ipín lãrin wọn: Emi ni ipín rẹ ati iní rẹ
lãrin awọn ọmọ Israeli.
21 Si kiyesi i, emi si ti fi gbogbo idamẹ-
wa ni Israeli fun awọn ọmọ Lefi ni iní,
nitori iṣẹ-ìsin wọn ti nwọn nṣe, ani iṣẹ-
ìsin agọ́ ajọ.
22 Awọn ọmọ Israeli kò si gbọdọ sunmọ
agọ́ ajọ, ki nwọn ki o má ba rù ẹ̀ṣẹ, ki
nwọn má ba kú.
23 Ṣugbọn awọn ọmọ Lefi ni ki o ma ṣe
iṣẹ-ìsin agọ́ ajọ, awọn ni yio si ma rù ẹ̀ṣẹ
wọn: ìlana lailai ni ni iran-iran nyin, ati
lãrin awọn ọmọ Israeli, nwọn kò gbọdọ ní
ilẹ-iní.
24 Nitori idamẹwa awọn ọmọ Israeli, ti
nwọn múwa li ẹbọ igbesọsoke fun Oluwa,
ni mo ti fi fun awọn ọmọ Lefi lati ní:
nitorina ni mo ṣe wi fun wọn pe, Nwọn
kò gbọdọ ní ilẹ-iní lãrin awọn ọmọ Israeli.
25 Oluwa si sọ fun Mose pe,
26 Si sọ fun awọn ọmọ Lefi, ki o si wi
fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba ngbà idamẹ-
wa ti mo ti fi fun nyin ni ilẹ-iní nyin lọwọ
awọn ọmọ Israeli, nigbana ni ki ẹnyin ki o
mú ẹbọ igbesọsoke ninu rẹ̀ wá fun Oluwa,
idamẹwa ninu idamẹwa na.
27 A o si kà ẹbọ igbesọsoke nyin yi si
nyin, bi ẹnipe ọkà lati ilẹ ipakà wá, ati bi
ọti lati ibi ifunti wá.
28 Bayi li ẹnyin pẹlu yio ma mú ẹbọ
igbesọsoke wá fun Oluwa ninu gbogbo
idamẹwa nyin, ti ẹnyin ngbà lọwọ awọn
ọmọ Israeli; ki ẹnyin ki o si mú ẹbọ igbe-
sọsoke Oluwa ninu rẹ̀ tọ̀ Aaroni alufa wá.
29 Ninu gbogbo ẹ̀bun nyin ni ki ẹnyin
ki o si mú gbogbo ẹbọ igbesọsoke Oluwa
wá, ninu gbogbo eyiti o dara, ani eyiti a
yàsimimọ́ ninu rẹ̀.
30 Nitorina ki iwọ ki o wi fun wọn pe,
Nigbati ẹnyin ba fi eyiti o dara ninu rẹ̀ ṣe
ẹbọ igbesọsoke, nigbana ni ki a kà a fun
awọn ọmọ Lefi bi ọkà ilẹ-ipakà, ati bi ibisi
ibi-ifunti.
31 Ẹnyin o si jẹ ẹ ni ibi gbogbo, ati
ẹnyin ati awọn ara ile nyin: nitoripe ère
nyin ni fun iṣẹ-ìsin nyin ninu agọ́ ajọ.
32 Ẹnyin ki yio si rù ẹ̀ṣẹ nitori rẹ̀,
nigbati ẹnyin ba fi eyiti o dara ninu rẹ̀ ṣe
ẹbọ igbesọsoke: bẹ̃li ẹnyin kò gbọdọ bà
ohun mimọ́ awọn ọmọ Israeli jẹ́, ki ẹnyin
ki o má ba kú.

Digitized by Google

## ORI 19.

OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni pe,

2 Eyi ni ìlana ofin, ti OLUWA palaṣẹ, wipe, Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki nwọn ki o mú ẹgbọrọ abomalu pupa kan tọ̀ ọ wá, alailabawọ́n, ati alailabùkun, ati lara eyiti a kò ti dì àjaga mọ́:

3 Ki ẹnyin si fi i fun Eleasari alufa, ki on ki o mú u jade lọ sẹhin ibudó, ki ẹnikan ki o si pa a niwaju rẹ̀:

4 Ki Eleasari alufa ki o fi iká rẹ̀ mú ninu ẹ̀jẹ rẹ̀, ki o si fi ninu ẹ̀jẹ rẹ̀ wọ́n iwaju agọ́ ajọ ni ìgba meje.

5 Ki ẹnikan ki o si sun ẹgbọrọ abomalu na li oju rẹ̀; awọ rẹ̀, ati ẹran rẹ̀ ati ẹ̀jẹ rẹ̀, pẹlu igbẹ́ rẹ̀, ni ki o sun:

6 Ki alufa na ki o mú igi opepe, ati hissopu, ati ododó, ki o si jù u sãrin ẹgbọrọ abomalu ti a nsun.

7 Nigbana ni ki alufa na ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, lẹhin na ki o si wá si ibudó, ki alufa na ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

8 Ki ẹniti o sun u ki o si fọ̀ aṣọ rẹ̀ ninu omi, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

9 Ki ọkọnrin kan ti o mọ́ ki o si kó ẽru ẹgbọrọ abomalu na, ki o si kó o jọ si ibi kan ti o mọ́ lẹhin ibudó, ki a si pa a mọ́ fun ijọ awọn ọmọ Israeli fun omi ìyasapakan: ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni.

10 Ki ẹniti o si kó ẽru ẹgbọrọ abomalu na ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ: yio si jẹ́ ìlana titilai, fun awọn ọmọ Israeli, ati fun alejò ti nṣe atipo ninu wọn.

11 Ẹniti o ba fọwọkàn okú ẹnikan, ki o jẹ́ alaimọ nijọ́ meje.

12 Ki oluwarẹ̀ ki o fi i wẹ̀ ara rẹ̀ mọ́ ni ijọ́ kẹta, ati ni ijọ́ keje yio di mimọ́: ṣugbọn bi kò ba wẹ̀ ara rẹ̀ ni ijọ́ kẹta, njẹ ni ijọ́ keje ki yio di mimọ́.

13 Ẹnikẹni ti o ba fọwọkàn okú ẹnikan ti o kú, ti kò si wẹ̀ ara rẹ̀ mọ́, o bà agọ́ OLUWA jẹ́; ọkàn na li a o si ke kuro ninu Israeli: nitoriti a kò wọ́n omi ìyasapakan si i lara, alaimọ́ li o jẹ́; aimọ́ rẹ̀ mbẹ lara rẹ̀ sibẹ̀,

14 Eyi li ofin na, nigbati enia kan ba kú ninu agọ́ kan: gbogbo ẹniti o wọ̀ inu agọ́ na, ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu agọ́ na, yio jẹ́ alaimọ́ ni ijọ́ meje.

15 Ati ohun-èlo gbogbo ti o ṣi silẹ, ti kò ní ideri lori rẹ̀, alaimọ́ ni.

16 Ẹnikẹni ti o ba si fọwọkàn ẹnikan ti a fi idà pa ni gbangba igbẹ́, tabi okú kan, tabi egungun ẹnikan, tabi isà-okú, yio jẹ́ alaimọ́ ni ijọ́ meje.

17 Ati fun ẹni aimọ́ kan ki nwọn ki o mú ninu ẽru sisun ẹbọ ẹ̀ṣẹ nì, ki a si bù omi ti nṣàn si i ninu ohun-èlo kan:

18 Ki ẹnikan ti o mọ́ ki o si mú hissopu, ki o si tẹ̀ ẹ bọ̀ inu omi na, ki o si fi i wọ́n agọ́ na, ati ohun-èlo gbogbo, ati sara awọn enia ti o wà nibẹ̀, ati sara ẹniti o fọwọkàn egungun kan, tabi ẹnikan ti a pa, tabi ẹnikan ti o kú, tabi isà-okú:

19 Ki ẹniti o mọ́ na ki o si bùwọ́n alaimọ́ na ni ijọ́ kẹta, ati ni ijọ́ keje: ati ni ijọ́ keje ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ mọ́; ki o si fọ̀ aṣọ rẹ̀, ki o si wẹ̀ ara rẹ̀ ninu omi, yio si di mimọ́ li aṣalẹ.

20 Ṣugbọn ẹniti o ba jẹ́ alaimọ́, ti kò ba wẹ̀ ara rẹ̀ mọ́, ọkàn na li a o ke kuro ninu ijọ, nitoriti o bà ibi-mimọ́ OLUWA jẹ́: a kò si ta omi ìyasapakan si i lara; alaimọ́ li on.

21 Yio si ma jẹ́ ìlana lailai fun wọn, pe ẹniti o ba bú omi ìyasapakan wọ́n ẹni, ki o fọ̀ aṣọ rẹ̀; ati ẹniti o si fọwọkàn omi ìyasapakan na yio jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ́.

22 Ati ohunkohun ti ẹni aimọ́ na ba si farakàn, yio jẹ́ alaimọ́; ọkàn ti o ba si farakàn a, yio jẹ́ alaimọ́ titi di aṣalẹ.

## ORI 20.

AWỌN ọmọ Israeli si wá, ani gbogbo ijọ, si aginjù Sini li oṣù kini: awọn enia na si joko ni Kadeṣi; Miriamu si kú nibẹ̀, a si sin i nibẹ̀.

2 Omi kò si sí fun ijọ: nwọn si kó ara wọn jọ pọ̀ si Mose ati si Aaroni.

3 Awọn enia si mbá Mose sọ̀, nwọn si wipe, Awa iba kuku ti kú nigbati awọn arakọnrin wa kú niwaju OLUWA!

4 Ẽha si ti ṣe ti ẹnyin fi mú ijọ OLUWA wá si aginjù yi, ki awa ati ẹran wá ki o kú nibẹ̀?

5 Ẽha si ti ṣe ti ẹnyin fi mú wa gòke ti Egipti wá, lati mú wa wá si ibi buburu yi? ki iṣe ibi irugbìn, tabi ti ọpọtọ, tabi ti àjara, tabi ti pomegranate; bẹ̃ni kò sí omi lati mu.

6 Mose ati Aaroni si lọ kuro niwaju ijọ si ẹnu-ọ̀na agọ́ ajọ, nwọn si doju wọn bolẹ: ogo OLUWA si hàn si wọn.

7 OLUWA si sọ fun Mose pe,

8 Mú ọpá nì, ki o si pe ijọ̀ awọn enia jọ, iwọ, ati Aaroni arakọnrin rẹ, ki ẹ sọ̀rọ si apata nì li oju wọn, yio si tú omi rẹ̀ jade; iwọ o si mú omi lati inu apata na jade fun

Digitized by Google

wọn wá: iwọ o si fi fun ijọ ati fun ẹran
wọn mu.
9 Mose si mú ọpá na lati iwaju OLUWA
lọ, bi o ti fun u li aṣẹ.
10 Mose ati Aaroni si pe ijọ awọn enia
jọ niwaju apata na, o si wi fun wọn pe,
Ẹ gbọ́ nisisiyi, ẹnyin ọlọtẹ; ki awa ki
o ha mú omi lati inu apata yi fun nyin wá
bi?
11 Mose si gbé ọwọ́ rẹ̀ soke, o si fi ọpá
rẹ̀ lù apata na lẹ̃meji: omi si tú jade li
ọ̀pọlọpọ, ijọ awọn enia si mu, ati ẹran wọn
pẹlu.
12 OLUWA si sọ fun Mose ati fun
Aaroni pe, Nitoriti ẹnyin kò gbà mi gbọ́,
lati yà mi simimọ́ loju awọn ọmọ Israeli,
nitorina ẹnyin ki yio mú ijọ awọn enia yi
lọ si ilẹ na ti mo fi fun wọn.
13 Wọnyi li omi Meriba; nitoriti awọn
ọmọ Israeli bá OLUWA sọ̀, o si di ẹni ìya-
simimọ́ ninu wọn.
14 Mose si rán onṣẹ lati Kadeṣi si ọba
Edomu, wipe, Bayi ni Israeli arakọnrin
rẹ wi, Iwọ sá mọ̀ gbogbo ìrin ti o bá wa:
15 Bi awọn baba wa ti sọkalẹ lọ si Egipti,
ti awa si ti gbé Egipti ni ìgba pipẹ; awọn
ara Egipti si ni wa lara, ati awọn baba wa:
16 Nigbati awa si kepè OLUWA, o gbọ́
ohùn wa, o si rán angeli kan, o si mú wa
lati Egipti jade wá; si kiyesi i, awa mbẹ
ni Kadeṣi, ilu kan ni ipinlẹ àgbegbe rẹ:
17 Jẹ ki awa ki o là ilẹ rẹ kọja lọ, awa
bẹ̀ ọ: awa ki yio là inu oko rẹ, tabi inu ọgbà-
àjara, bẹ̃li awa ki yio mu ninu omi kanga:
ọ̀na opópo ọba li awa o gbà, awa ki o yà si
ọwọ́ ọtún tabi si òsi, titi awa o fi kọja ipinlẹ
rẹ.
18 Edomu si wi fun u pe, Iwọ ki yio kọ-
ja lọdọ mi, ki emi ki o má ba jade si ọ ti
emi ti idà.
19 Awọn ọmọ Israeli si wi fun u pe, Ọ̀na
opópo ọba li awa o gbà: bi awa ba mu ninu
omi rẹ, emi ati ẹran mi, njẹ emi o san owo
rẹ̀: laiṣe ohun miran, ki nsá fi ẹsẹ̀ mi là
ilẹ rẹ kọja.
20 O si wipe, Iwọ ki yio là ilẹ kọja.
Edomu si mú ọ̀pọ enia jade tọ̀ ọ wá pẹlu
ọwọ́ agbara.
21 Bẹ̃li Edomu kọ̀ lati fi ọ̀na fun Israeli
li àgbegbe rẹ̀: Israeli si ṣẹri kuro lọdọ rẹ̀.
22 Awọn ọmọ Israeli, ani gbogbo ijọ si
ṣí kuro ni Kadeṣi, nwọn si wá si òke Hori.
23 OLUWA si sọ fun Mose ati fun Aaroni
li òke Hori li àgbegbe ilẹ Edomu wipe,
24 A o kó Aaroni jọ pẹlu awọn enia rẹ̀:
nitoripe on ki yio wọ̀ inu ilẹ na ti mo fi
fun awọn ọmọ Israeli, nitoriti ẹnyin ṣọ̀tẹ
si aṣẹ mi, nibi omi Meriba.
25 Mú Aaroni ati Eleasari ọmọ rẹ̀, ki o
si mú wọn wá si ori òke Hori:
26 Ki o si bọ́ Aaroni li aṣọ rẹ̀, ki o si fi
wọn wọ̀ Eleasari ọmọ rẹ̀: a o si kó Aaroni
jọ pẹlu awọn enia rẹ̀, yio si kú nibẹ̀.
27 Mose si ṣe bi OLUWA ti fun u li aṣẹ:
nwọn si gòke lọ si ori òke Hori li oju gbo-
gbo ijọ.
28 Mose si bọ́ Aaronì li aṣọ rẹ̀, o si fi
wọn wọ̀ Eleasari ọmọ rẹ̀; Aaroni si kú nibẹ̀
li ori òke na: Mose ati Eleasari si sọkalẹ
lati ori òke na wá.
29 Nigbati gbogbo ijọ ri pe Aaroni kú,
nwọn ṣọfọ Aaroni li ọgbọ̀n ọjọ́, ani gbogbo
ile Israeli.

## ORI 21.

ẸNI ara Kenaani, ọba Aradi, ti ngbé ìha
Gusù, gbọ́ pe Israeli gbà ọ̀na amí yọ;
nigbana li o bá Israeli jà, o si mú ninu
wọn ni igbekun.
2 Israeli si jẹ́ ẹjẹ́ fun OLUWA, wipe, Bi
iwọ ba fi awọn enia yi lé mi lọwọ nitõtọ,
njẹ emi o run ilu wọn patapata.
3 OLUWA si gbọ́ ohùn Israeli, o si fi
awọn ara Kenaani tọrẹ, nwọn si run wọn
patapata, ati ilu wọn: o si sọ orukọ ibẹ̀ na
ni Horma.
4 Nwọn si rìn lati òke Hori lọ li ọ̀na
Okun Pupa, lati yi ilẹ Edomu ká: sũru si
tán awọn enia na pupọ̀pupọ nitori ọ̀na na.
5 Awọn enia na si bá Ọlọrun, ati Mose
sọ̀ pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi mú wa gòke lati
Egipti jade wá lati kú li aginjù? nitoripe
àkara kò sí, bẹ̃ni kò sí omi; onjẹ futẹfutẹ
yi si sú ọkàn wa.
6 OLUWA si rán ejò amubina si awọn
enia na, nwọn si bù awọn enia na ṣan;
ọ̀pọlọpọ ninu Israeli si kú.
7 Nitorina li awọn enia na ṣe tọ̀ Mose
wá, nwọn si wipe, Awa ti ṣẹ̀, nitoriti awa
ti bá OLUWA ati iwọ sọ̀; gbadura si OLU-
WA ki o mú ejò wọnyi kuro lọdọ wa. Mose
si gbadura fun awọn enia na.
8 OLUWA si wi fun Mose pe, Rọ ejò
amubina kan, ki o si fi i sori ọpá-gigùn
kan: yio si ṣe, olukuluku ẹniti ejò ba
bùṣan, nigbati o ba wò o, yio yè.
9 Mose si rọ ejò idẹ kan, o si fi i sori
ọpá-gigùn na: o si ṣe, pe bi ejò kan ba bù
enia kan ṣan, nigbati o ba wò ejò idẹ na
on a yè.
10 Awọn ọmọ Israeli si ṣí siwaju, nwọn
si dó ni Obotu.

Digitized by Google

11 Nwọn si ṣi lati Obotu lọ, nwọn si dó
si Iye-abarimu, li aginjù ti mbẹ niwaju
Moabu, ni ìha ìla-õrùn.
12 Lati ibẹ̀ lọ nwọn ṣí, nwọn si dó si
afonifoji Seredi.
13 Lati ibẹ̀ lọ nwọn ṣí, nwọn si dó si ìha
keji Arnoni, ti mbẹ li aginjù, ti o ti àgbe-
gbe awọn ọmọ Amori wá: nitoripe Arnoni
ni ipinlẹ Moabu, lãrin Moabu ati awọn
Amori.
14 Nitorina ni a ṣe wi ninu iwé Ogun
OLUWA pe, Ohun ti o ṣe li Okun Pupa, ati
li odò Arnoni.
15 Ati ni iṣàn-odò nì ti o darí si ibujoko
Ari, ti o si gbè ipinlẹ Moabu.
16 Lati ibẹ̀ nwọn si lọ si Beeri: eyinì ni
kanga eyiti OLUWA sọ fun Mose pe, Pe
awọn enia jọ, emi o si fun wọn li omi.
17 Nigbana ni Israeli kọrin yi pe: Sun
jade iwọ kanga; ẹ ma kọrin si i:
18 Kanga na, ti awọn olori wà, ti awọn
ọlọlá awọn enia si fi ọpá-alade na, ati ọpá
wọn wà. Ati lati aginjù na, nwọn lọ si
Mattana.
19 Ati lati Mattana nwọn lọ si Nahali-
eli: ati lati Nahalieli nwọn lọ si Bamotu:
20 Ati lati Bamotu li afonifoji nì, ti
mbẹ ni ilẹ Moabu, si òke Pisga, ti o si kọ-
jusi aginjù.
21 Israeli si rán onṣẹ si Sihoni ọba awọn
ọmọ Amori, wipe,
22 Jẹ ki emi là ilẹ rẹ kọja lọ: awa ki
yio yà sinu oko, tabi ọgba-àjara; awa ki
yio mu ninu omi kanga: ọ̀na opópo ọba li
a o gbà, titi awa o fi kọja ipinlẹ rẹ.
23 Sihoni kò si jẹ ki Israeli ki o là
àgbegbe rẹ̀ kọja: ṣugbọn Sihoni kó gbogbo
awọn enia rẹ̀ jọ, nwọn si jade tọ̀ Israeli lọ
li aginjù, o si wá si Jahasi, o bá Israeli jà.
24 Israeli si fi oju idà kọlù u, o si gbà
ilẹ rẹ̀ lati Arnoni lọ dé Jaboku, ani dé ti
awọn ọmọ Ammoni; nitoripe ipinlẹ ti awọn
ọmọ Ammoni lí agbara.
25 Israeli si gbà gbogbo ilunla wọnni:
Israeli si joko ninu gbogbo ilunla ti awọn
ọmọ Amori, ni Heṣboni, ati ni ilu rẹ̀ gbo-
gbo.
26 Nitoripe Heṣboni ni ilunla Sihoni
ọba awọn ọmọ Amori, ẹniti o ti bá ọba
Moabu atijọ jà, ti o si gbà gbogbo ilẹ rẹ̀ li
ọwọ́ rẹ̀, titi dé Arnoni.
27 Nitorina awọn ti nkọrin owe a ma
wipe, Wá si Heṣboni, jẹ ki a tẹ̀ ilunla
Sihoni dó ki a si tun fi idi rẹ̀ mulẹ:
28 Nitoriti iná kan ti Heṣboni jade lọ,
ọwọ́-iná kan lati ilunla Sihoni: o si run
Ari ti Moabu, ati awọn oluwa ibi giga
Arnoni.
29 Egbé ni fun iwọ, Moabu! Ẹ gbé,
ẹnyin enia Kemoṣi: on ti fi awọn ọmọ rẹ̀
ọkọnrin bi isansa, ati awọn ọmọ rẹ̀ obirin
bi igbekun, fun Sihoni ọba awọn ọmọ
Amori.
30 Awa tafà si wọn; Heṣboni ṣegbé titi
dé Diboni, awa si ti run wọn titi dé Nofa,
ti o dé Medeba.
31 Bẹ̃li awọn ọmọ Israeli joko ni ilẹ
awọn ọmọ Amori.
32 Mose si rán enia lọ ṣe amí Jaseri,
nwọn si gbà ilu rẹ̀, nwọn si lé awọn ọmọ
Amori ti o wà nibẹ̀.
33 Nwọn si yipada, nwọn si gòke lọ li
ọ̀na Baṣani: Ogu ọba Baṣani si jade tọ̀ wọn
lọ, on, ati gbogbo awọn enia rẹ̀, si ogun ni
Edrei.
34 OLUWA si wi fun Mose pe, Máṣe bẹ̀ru
rẹ̀: nitoripe mo ti fi on lé ọ lọwọ, ati gbo-
gbo awọn enia rẹ̀, ati ilẹ rẹ̀; ki iwọ ki o si
ṣe si i bi iwọ ti ṣe si Sihoni ọba awọn ọmọ
Amori, ti ngbé Heṣboni.
35 Bẹ̃ni nwọn si kọlù u, ati awọn ọmọ
rẹ̀, ati gbogbo awọn enia rẹ̀, titi kò fi kù
ọkan silẹ fun u lãye: nwọn si gbà ilẹ rẹ̀.

## ORI 22.

AWỌN ọmọ Israeli si ṣí, nwọn si dó si pẹ-
tẹlẹ̀ Moabu li apa keji Jordani ti o
kọjusi Jeriko.
2 Balaki ọmọ Sippori si ri gbogbo eyiti
Israeli ti ṣe si awọn ọmọ Amori.
3 Moabu si bẹ̀ru awọn enia na gidigidi,
nitoriti nwọn pọ̀: aisimi si bá Moabu nitori
awọn ọmọ Israeli.
4 Moabu si wi fun awọn àgba Midiani
pe, Nisisiyi li awọn ẹgbẹ yi yio lá ohun
gbogbo ti o yi wa ká, bi akọmalu ti ilá ko-
riko igbẹ́. Balaki ọmọ Sippori si jẹ́ ọba
awọn ara Moabu ni ìgbana.
5 O si ránṣẹ si Balaamu ọmọ Beori si
Petori, ti o wà lẹba Odò, si ilẹ awọn ọmọ
enia rẹ̀, lati pè e wá, wipe, Wò o, awọn
enia kan ti ilẹ Egipti jade wá: si kiyesi i,
nwọn bò oju ilẹ, nwọn si joko tì mi:
6 Njẹ nisisiyi wá, emi bẹ̀ ọ, fi awọn enia
yi bú fun mi; nitoriti nwọn lí agbara jù
fun mi; bọya emi o bori, ki awa ki o kọlù
wọn, ki emi ki o le lé wọn lọ kuro ni ilẹ
yi: nitoriti emi mọ̀ pe ibukún ni fun ẹniti
iwọ ba bukún, ifibú si ni ẹniti iwọ ba fibú.
7 Ati awọn àgba Moabu, ati awọn àgba
Midiani dide lọ ti awọn ti ọrẹ ìbere-afọṣẹ li



Digitized by Google

ọwọ́ wọn; nwọn si tọ̀ Balaamu wá, nwọn si sọ ọ̀rọ Balaki fun u.

8 O si wi fun wọn pe, Ẹ wọ̀ nihin li alẹ yi, emi o si mú ọ̀rọ pada tọ̀ nyin wá, bi OLUWA yio ti sọ fun mi: awọn ijoye Moabu si wọ̀ sọdọ Balaamu.

9 Ọlọrun si tọ̀ Balaamu wá, o si wipe, Awọn ọkọnrin wo ni wọnyi lọdọ rẹ?

10 Balaamu si wi fun Ọlọrun pe, Balaki ọmọ Sippori, ọba Moabu, li o ranṣẹ si mi pe,

11 Kiyesi i, awọn enia kan ti ilẹ Egipti jade wá, ti o bò oju ilẹ: wá nisisiyi, fi wọn bú fun mi; bọya emi o le bá wọn jà, emi a si lé wọn lọ.

12 Ọlọrun si wi fun Balaamu pe, Iwọ kò gbọdọ bá wọn lọ: iwọ kò gbọdọ fi awọn enia na bú: nitoripe ẹni ibukún ni nwọn.

13 Balaamu si dide li owurọ̀, o si wi fun awọn ijoye Balaki pe, Ẹ ma ba ti nyin lọ si ilẹ nyin: nitoriti OLUWA kọ̀ lati jẹ ki mbá nyin lọ.

14 Awọn ijoye Moabu si dide, nwọn si tọ̀ Balaki lọ, nwọn si wipe, Balaamu kọ̀ lati bá wa wá.

15 Balaki si tun rán awọn ijoye si i, ti o si lí ọlá jù wọn lọ.

16 Nwọn tọ̀ Balaamu wá, nwọn si wi fun u pe, Bayi ni Balaki ọmọ Sippori wi pe, Emi bẹ̀ ọ, máṣe jẹ ki ohun kan ki o di ọ lọwọ lati tọ̀ mi wá:

17 Nitoripe, emi o sọ ọ di ẹni nla gidigidi, emi o si ṣe ohunkohun ti iwọ wi fun mi: nitorina wá, emi bẹ̀ ọ, fi awọn enia yi bú fun mi.

18 Balaamu si dahùn o si wi fun awọn iranṣẹ Balaki pe, Balaki iba fẹ́ fun mi ni ile rẹ̀ ti o kún fun fadaká ati wurà, emi kò le rekọja ọ̀rọ OLUWA Ọlọrun mi, lati ṣe ohun kekere tabi nla.

19 Njẹ nisisiyi, emi bẹ̀ nyin, ẹ wọ̀ nihin pẹlu li oru yi, ki emi ki o le mọ̀ eyiti OLUWA yio wi fun mi si i.

20 Ọlọrun si tọ̀ Balaamu wá li oru, o si wi fun u pe, Bi awọn ọkọnrin na ba wá pè ọ, dide, bá wọn lọ; ṣugbọn kìki ọ̀rọ ti emi o sọ fun ọ, eyinì ni ki iwọ ki o ṣe.

21 Balaamu si dide li owurọ̀, o si dì kẹtẹkẹtẹ rẹ̀ ni gãri, o si bá awọn ijoye Moabu lọ.

22 Ibinu Ọlọrun si rú nitoriti o lọ: angeli OLUWA si duro loju ọ̀na lati di i lọ́na. Njẹ on gùn kẹtẹkẹtẹ rẹ̀, awọn iranṣẹ rẹ̀ mejeji si wà pẹlu rẹ̀.

23 Kẹtẹkẹtẹ na si ri angeli OLUWA duro loju ọ̀na, idà rẹ̀ fifàyọ si wà li ọwọ́ rẹ̀: kẹtẹkẹtẹ na si yà kuro loju ọ̀na, o si wọ̀ inu igbẹ́: Balaamu si lù kẹtẹkẹtẹ na, lati darí rẹ̀ soju ọ̀na.

24 Nigbana ni angeli OLUWA duro li ọna toro ọgbà-àjara meji, ogiri mbẹ ni ìha ihin, ati ogiri ni ìha ọhún.

25 Kẹtẹkẹtẹ na si ri angeli OLUWA, o fún ara rẹ̀ mọ́ ogiri, o si fún ẹsẹ̀ Balaamu mọ́ ogiri: on si tun lù u.

26 Angeli OLUWA si tun sun siwaju, o si tun duro ni ibi toro kan, nibiti àye kò sí lati yà si ọwọ́ ọtún tabi si òsi.

27 Nigbati kẹtẹkẹtẹ na si ri angeli OLUWA, o wólẹ̀ labẹ Balaamu: ibinu Balaamu si rú pupọ̀, o si fi ọpá lù kẹtẹkẹtẹ na.

28 OLUWA si là kẹtẹkẹtẹ na li ohùn o si wi fun Balaamu pe, Kini mo fi ṣe ọ, ti iwọ fi lù mi ni ìgba mẹta yi?

29 Balaamu si wi fun kẹtẹkẹtẹ na pe, Nitoriti iwọ fi mi ṣẹsin: idà iba wà li ọwọ́ mi, nisisiyi li emi iba pa ọ.

30 Kẹtẹkẹtẹ na si wi fun Balaamu pe, Kẹtẹkẹtẹ rẹ ki emi iṣe, ti iwọ ti ngùn lati ìgba ti emi ti ṣe tirẹ titi di oni? emi a ha ma ṣe si ọ bẽ rí? On si dahùn wipe, Ndao.

31 Nigbana ni OLUWA là Balaamu li oju, o si ri angeli OLUWA duro loju ọ̀na, idà rẹ̀ fifàyọ si wà li ọwọ́ rẹ̀: o si tẹ̀ ori ba, o si doju rẹ̀ bolẹ.

32 Angeli OLUWA si wi fun u pe, Ẽṣe ti iwọ fi lù kẹtẹkẹtẹ rẹ ni ìgba mẹta yi? Kiyesi i, emi jade wá lati di ọ lọna, nitori ọ̀na rẹ lòdi niwaju mi.

33 Kẹtẹkẹtẹ na si ri mi, o si yà fun mi ni ìgba mẹta yi: bikoṣe bi o ti yà fun mi, pipa ni emi iba pa ọ, emi a si dá on si.

34 Balaamu si wi fun angeli OLUWA pe, Emi ti ṣẹ̀; nitori emi kò mọ̀ pe iwọ duro dè mi li ọ̀na; njẹ bi kò ba ṣe didùn inu rẹ, emi o pada.

35 Angeli OLUWA si wi fun Balaamu pe, Ma bá awọn ọkọnrin na lọ: ṣugbọn kìki ọ̀rọ ti emi o sọ fun ọ, eyinì ni ki iwọ ki o sọ. Bẽni Balaamu bá awọn ijoye Balaki lọ.

36 Nigbati Balaki gbọ́ pe Balaamu dé, o jade lọ ipade rẹ̀ ni Ilu Moabu, ti mbẹ ni àgbegbe Arnoni, ti iṣe ìpẹkun ipinlẹ na.

37 Balaki si wi fun Balaamu pe, Emi kò ha ranṣẹ kanjukanju si ọ lati pè ọ? ẽṣe ti iwọ kò fi tọ̀ mi wá? emi kò ha to lati sọ ọ di ẹni nla?

38 Balaamu si wi fun Balaki pe, Kiyesi i, emi tọ̀ ọ wá: emi ha lí agbara kan nisisiyi rára lati wi ohun kan? ọ̀rọ ti OLUWA fi si mi li ẹnu, on li emi o sọ.

Digitized by Google

39 Balaamu si bá Balaki lọ, nwọn si wá si Kiriati-husotu.
40 Balaki si rubọ akọmalu ati agutan, o si ranṣẹ si Balaamu, ati si awọn ijoye ti mbẹ pẹlu rẹ̀.
41 O si ṣe ni ijọ́ keji, ni Balaki mú Balaamu, o si mú u wá si ibi giga Baali, ki o ba le ri apakan awọn enia na lati ibẹ̀ lọ.

## ORI 23.

BALAAMU si wi fun Balaki pe, Mọ pẹpẹ meje fun mi nihin, ki o si pèse akọmalu meje, ati àgbo meje fun mi nihin.
2 Balaki si ṣe bi Balaamu ti wi; ati Balaki ati Balaamu fi akọmalu kan ati àgbo kan rubọ lori pẹpẹ kọkan.
3 Balaamu si wi fun Balaki pe, Duro tì ẹbọ sisun rẹ, emi o si lọ; bọya OLUWA yio wá pade mi: ohunkohun ti o si fihàn mi emi o wi fun ọ. O si lọ si ibi giga kan.
4 Ọlọrun si pade Balaamu: o si wi fun u pe, Emi ti pèse pẹpẹ meje silẹ, mo si ti fi akọmalu kan ati àgbo kan rubọ lori pẹpẹ kọkan.
5 OLUWA si fi ọ̀rọ si Balaamu li ẹnu, o si wipe, Pada tọ̀ Balaki lọ, bayi ni ki iwọ ki o si sọ.
6 O si pada tọ̀ ọ lọ, si kiyesi i, on duro tì ẹbọ sisun rẹ̀, on ati gbogbo awọn ijoye Moabu.
7 O si bẹrẹsi owe rẹ̀, o si wipe, Balaki ọba Moabu mú mi lati Aramu wá, lati òkenla ìla-õrùn wá, wipe, Wá, fi Jakobu bú fun mi, si wá, ki o fi Israeli ré.
8 Emi o ti ṣe fibú, ẹniti Ọlọrun kò fibú? tabi emi o si ti ṣe firé, ẹniti OLUWA kò fi ré?
9 Nitoripe lati ori apata wọnni ni mo ri i, ati lati òke wọnni ni mo wò o: kiyesi i, awọn enia yi yio dágbé, a ki yio si kà wọn kún awọn orilẹ-ède.
10 Tali o le kà erupẹ Jakobu, ati iye idamẹrin Israeli? Jẹ ki emi ki o kú ikú olododo, ki igbẹhin mi ki o si dabi tirẹ̀!
11 Balaki si wi fun Balaamu pe, Kini iwọ nṣe si mi yi? mo mú ọ wá lati fi awọn ọtá mi bú, si kiyesi i, iwọ si sure fun wọn patapata.
12 On si dahùn o si wipe, Emi ha le ṣe aiṣọra lati sọ eyiti OLUWA fi si mi li ẹnu bi?
13 Balaki si wi fun u pe, Emi bẹ̀ ọ, bá mi lọ si ibomiran, lati ibiti iwọ o le ri wọn; kìki apakan wọn ni iwọ o ri, iwọ ki yio si ri gbogbo wọn tán; ki o si fi wọn bú fun mi lati ibẹ̀ lọ.
14 O si mú u wá si igbẹ Sofimu sori oke Pisga, o si mọ pẹpẹ meje, o si fi akọmalu kan ati àgbo kan rubọ lori pẹpẹ kọkan.
15 On si wi fun Balaki pe, Duro nihin tì ẹbọ sisun rẹ, emi o si lọ ipade OLUWA lọhùn yi.
16 OLUWA si pade Balaamu o si fi ọ̀rọ si i li ẹnu, wipe, Tun pada tọ̀ Balaki lọ, ki o si wi bayi.
17 O si tọ̀ ọ wá, kiyesi i, o duro tì ẹbọ sisun rẹ̀, ati awọn ijoye Moabu pẹlu rẹ̀. Balaki si bi i pe, Kini OLUWA sọ?
18 O si bẹrẹsi owe rẹ̀, o si wipe, Dide, Balaki, ki o si gbọ́; ki o si fetisi mi, iwọ ọmọ Sipporu:
19 Ọlọrun ki iṣe enia ti yio fi ṣeké; bẹ̃ni ki iṣe ọmọ enia ti yio fi ronupiwada: a ma wi, ki o má si ṣe e bi? tabi a ma sọ̀rọ ki o má mu u ṣẹ?
20 Kiyesi i, emi gbà aṣẹ ati sure: on si ti sure, emi kò si le yi i.
21 On kò ri ẹ̀ṣẹ ninu Jakobu, bẹ̃ni kò ri ibi ninu Israeli: OLUWA Ọlọrun rẹ̀ pẹlu rẹ̀, ihó-ayọ ọba si mbẹ ninu wọn.
22 Ọlọrun mú wọn lati Egipti jade wá; o ní agbara bi ti agbanrere.
23 Nitõtọ, kò sí ìfaiya si Jakobu, bẹ̃ni kò sí afọṣẹ si Israeli: nisisiyi li a o ma wi niti Jakobu ati niti Israeli, Ohun ti Ọlọrun ṣe!
24 Kiyesi i, awọn enia na yio dide bi abo-kiniun, yio si gbé ara rẹ̀ soke bi kiniun: on ki yio dubulẹ titi yio fi jẹ ohun ọdẹ, titi yio si fi mu ninu ẹ̀jẹ ohun pipa.
25 Balaki si wi fun Balaamu pe, Kuku má fi wọn bú, bẹ̃ni ki o máṣe sure fun wọn rára.
26 Ṣugbọn Balaamu dahùn, o si wi fun Balaki pe, Emi kò ha ti wi fun ọ pe, Gbogbo eyiti OLUWA ba sọ, on li emi o ṣe?
27 Balaki si wi fun Balaamu pe, Wá, emi bẹ̀ ọ, emi o mú ọ lọ si ibomiran; bọya yio wù Ọlọrun ki iwọ ki o fi wọn bú fun mi lati ibẹ̀ lọ.
28 Balaki si mú Balaamu wá sori òke Peoru, ti o kọjusi aginjù.
29 Balaamu si wi fun Balaki pe, Mọ pẹpẹ meje fun mi nihin, ki o si pèse akọmalu meje ati àgbo meje fun mi nihin.
30 Balaki si ṣe bi Balaamu ti wi, o si fi akọmalu kan ati àgbo kan rubọ lori pẹpẹ kọkan.

## ORI 24.

NIGBATI Balaamu ri pe o wù OLUWA lati bukún Israeli, on kò lọ mọ́ bi

Digitized by Google

ìgba iṣaju, lati wá ìfaiya, ṣugbọn o doju rẹ̀
kọ aginjù.
2 Balaamu si gbé oju rẹ̀ soke o si ri
Israeli dó gẹgẹ bi ẹya wọn ; ẹmi Ọlọrun si
wá sara rẹ̀.
3 O si bẹ̀rẹsi owe rẹ̀, o si wipe, Balaamu
ọmọ Beori nwi, ọkọnrin ti oju rẹ̀ ṣí nwi :
4 Ẹniti o gbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun nwi, ti o nri
iran Olodumare, ti o nṣubu lọ, ti oju rẹ̀ si ṣí.
5 Jakobu, agọ́ rẹ wọnyi ti dara tó, ati
ibugbé rẹ iwọ Israeli !
6 Bi afonifoji ni nwọn tẹ́ lọ bẹrẹ, bi ọgbà
lẹba odònla, bi igi aloe ti OLUWA gbìn, ati
bi igi kedari lẹba omi.
7 Omi o ṣàn jade lati inu agbè rẹ̀ wá, irú
rẹ̀ yio si wà ninu omi pupọ̀, ọba rẹ̀ yio si
ga jù Agagi lọ, ijọba rẹ̀ li a o si gbeleke.
8 Ọlọrun mú u lati Egipti jade wá ; o ní
agbara bi ti agbanrere : on o jẹ awọn orilẹ-
ède ti iṣe ọtá rẹ̀ run, yio si fọ́ egungun wọn,
yio si fi ọfà rẹ̀ ta wọn li atapoyọ.
9 O ba, o dubulẹ bi kiniun, ati bi abo-
kiniun : tani yio lé e dide ? Ibukún ni fun
ẹniti o sure fun ọ, ifibú si ni ẹniti o fi ọ
bú.
10 Ibinu Balaki si rú si Balaamu, o si fi
ọwọ́ lù ọwọ́ pọ̀ : Balaki si wi fun Balaamu
pe, Emi pè ọ lati fi awọn ọtá mi bú, si ki-
yesi i iwọ si súre fun wọn patapata ni ìgba
mẹta yi.
11 Njẹ nisisiyi sálọ si ibujoko rẹ : emi ti
rò lati sọ ọ di ẹni nla ; ṣugbọn kiyesi i,
OLUWA fà ọ sẹhin kuro ninu ọlá.
12 Balaamu si wi fun Balaki pe, Emi kò
ti sọ fun awọn onṣẹ rẹ pẹlu ti iwọ rán si
mi pe,
13 Bi Balaki tilẹ fẹ́ lati fi ile rẹ̀ ti o kún
fun fadakà ati wurá fun mi, emi kò le re-
kọja ọ̀rọ OLUWA, lati ṣe rere tabi buburu
lati inu ara mi wá ; ṣugbọn eyiti OLUWA
wi, eyina li emi o sọ ?
14 Njẹ nisisiyi si kiyesi i, emi nlọ sọdọ
awọn enia mi : wá, emi o si sọ fun ọ ohun
ti awọn enia yi yio ṣe si awọn enia rẹ li
ẹhin-ọla.
15 O si bẹ̀rẹsi owe rẹ̀, o si wipe, Balaamu
ọmọ Beori nwi, ọkọnrin ti oju rẹ̀ ṣí nwi :
16 Ẹniti o gbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun nwi, ti o si
mọ̀ imọ̀ Ọga-Ogo, ti o ri iran Olodumare,
ti o nṣubu lọ, ti oju rẹ̀ si ṣí :
17 Emi ri i, ṣugbọn ki iṣe nisisiyi : emi
si wò o, ṣugbọn kò sunmọtosi : irawọ kan
yio ti inu Jakobu jade wá, ọpa-alade kan
yio si ti inu Israeli dide, yio si kọlù awọn
igun Moabu, yio si ṣẹ́ gbogbo awọn ọmọ
irọkẹ̀kẹ.
18 Edomu yio si di iní, Seiri pẹlu yio si
di iní, fun awọn ọtá rẹ̀ ; Israeli yio si ṣe
iṣe-agbara.
19 Lati inu Jakobu li ẹniti yio ní ijọba
yio ti jade wá, yio si run ẹniti o kù ninu
ilunla.
20 Nigbati o si wò Amaleki, o si bẹ̀rẹsi
owe rẹ̀, o si wipe, Amaleki ni ekini ninu
awọn orilẹ-ède ; ṣugbọn igbẹhin rẹ̀ ni ki o
ṣegbé.
21 O si wò awọn ara Keni, o si bẹ̀rẹsi
owe rẹ̀, o si wipe, Agbara ni ibujoko rẹ, iwọ
si tẹ́ itẹ́ rẹ sinu okuta.
22 Ṣugbọn a o run awọn ara Keni, titi
awọn ara Aṣṣuri yio kó ọ lọ ni igbekùn.
23 O si bẹ̀rẹsi owe rẹ̀, o si wipe, A, tani
yio wà, nigbati Ọlọrun yio ṣe eyi !
24 Awọn ọkọ̀ yio ti ebute Kittimu wá,
nwọn o si pọn Aṣṣuri loju, nwọn o si pọn
Eberi loju, on pẹlu yio si ṣegbé.
25 Balaamu si dide, o si lọ o si pada si
ibujoko rẹ̀ ; Balaki pẹlu si ba ọ̀na rẹ̀ lọ.

## ORI 25.

ISRAELI si joko ni Ṣittimu, awọn enia
na si bẹ̀rẹsi iṣe panṣaga pẹlu awọn ọmọ-
birin Moabu :
2 Nwọn si pe awọn enia na si ẹbọ oriṣa
wọn ; awọn enia na si jẹ, nwọn si tẹriba fun
oriṣa wọn.
3 Israeli si dà ara rẹ̀ pọ̀ mọ́ Baali-peoru :
ibinu OLUWA si rú si Israeli.
4 OLUWA si sọ fun Mose pe, Mú gbogbo
awọn olori awọn enia na, ki o si so wọn rọ̀
si õrùn niwaju OLUWA, ki imuna ibinu
OLUWA ki o le yipada kuro lọdọ Israeli.
5 Mose si wi fun awọn onidajọ Israeli pe,
Ki olukuluku nyin ki o pa awọn enia rẹ̀ ti
o dàpọ mọ́ Baali-peoru.
6 Si kiyesi i, ọkan ninu awọn ọmọ Isra-
eli wá o si mú obirin Midiani kan tọ̀ awọn
arakọnrin rẹ̀ wá li oju Mose, ati li oju gbo-
gbo ijọ awọn ọmọ Israeli, ti nsọkun ni ẹnu-
ọ̀na agọ́ ajọ.
7 Nigbati Finehasi, ọmọ Eleasari, ọmọ
Aaroni alufa ri i, o dide lãrin ijọ, o si mú
ọ̀kọ kan li ọwọ́ rẹ̀ ;
8 O si tọ̀ ọkọnrin Israeli na lọ ninu agọ́,
o si fi gún awọn mejeji li agunyọ, ọkọnrin
Israeli na, ati obirin na ni inu rẹ̀. Arun
si da lãriu awọn ọmọ Israeli.
9 Awọn ti o si kú ninu àrun na jẹ́ ẹgba
mejila.
10 OLUWA si sọ fun Mose pe,
11 Finehasi, ọmọ Eleasari, ọmọ Aaroni
alufa ti yi ibinu mi pada kuro lara awọn

Digitized by Google

ọmọ Israeli, nipa itara rẹ̀ nitori mi lãrin
wọn, ki emi ki o máṣe run awọn ọmọ Isra-
eli ninu owú mi.
12 Nitorina wipe, Kiyesi i, emi fi majẹ-
mu alafia mi fun u.
13 Yio jẹ́ tirẹ̀ ati ti irú-ọmọ rẹ̀ lẹhin rẹ̀,
ani majẹmu iṣẹ-alufa titi-aiye; nitoriti o ṣe
itara fun Ọlọrun rẹ̀, o si ṣètutu fun awọn
ọmọ Israeli.
14 Njẹ orukọ ọkọnrin Israeli na ti a pa,
ani ti a pa pẹlu obirin Midiani na, a ma jẹ́
Simri, ọmọ Salu, olori ile kan ninu awọn
ọmọ Simeoni.
15 Orukọ obirin Midiani na ti a pa a si
ma jẹ́ Kosbi, ọmọbirin Suru; ti iṣe olori
awọn enia kan, ati ti ile kan ni Midiani.
16 OLUWA si sọ fun Mose pe,
17 Yọ awọn ara Midiani lẹnu, ki o si
kọlù wọn.
18 Nitoriti nwọn fi ẹ̀tan wọn yọ nyin
lẹnu, eyiti nwọn tàn nyin niti ọ̀ran Peori,
ati niti ọ̀ran Kosbi, ọmọ ijoye Midiani kan,
arabirin wọn, ẹniti a pa li ọjọ́ àrun nì niti
ọ̀ran Peori.

## ORI 26.

O SI ṣe lẹhin àrun na, ni OLUWA sọ fun
Mose ati fun Eleasari alufa ọmọ Aaroni
pe,
2 Kà iye gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli,
lati ẹni ogún ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ, gẹgẹ bi
ile awọn baba wọn, gbogbo awọn ti o le lọ
si ogun ni Israeli.
3 Mose ati Eleasari alufa si sọ fun wọn
ni pẹtẹlẹ̀ Moabu, lẹba Jordani leti Jeriko
pe,
4 Ẹ kà iye awọn enia na, lati ẹni ogún
ọdún lọ ati jù bẹ̃ lọ; bi OLUWA ti paṣẹ fun
Mose, ati fun awọn ọmọ Israeli, ti o ti ilẹ
Egipti jade wá.
5 Reubeni, akọ́bi Israeli: awọn ọmọ
Reubeni; Hanoki, lati ọdọ ẹniti idile awọn
ọmọ Hanoki ti wá: ti Pallu, idile awọn
ọmọ Pallu:
6 Ti Hesroni, idile awọn ọmọ Hesroni:
ti Karmi, idile awọn ọmọ Karmi.
7 Wọnyi ni idile awọn ọmọ Reubeni:
awọn ti a si kà ninu wọn jẹ́ ẹgba mọkanle-
logun o le ẹgbẹsan o din ãdọrin.
8 Ati awọn ọmọ Pallu; Eliabu.
9 Ati awọn ọmọ Eliabu; Nemueli, ati
Datani, ati Abiramu. Eyi ni Datani ati
Abiramu na, ti nwọn lí okiki ninu ijọ, ti
nwọn bá Mose ati Aaroni jà ninu ẹgbẹ Kora,
nigbati nwọn bá OLUWA jà.
10 Ti ilẹ si là ẹnu rẹ̀, ti o si gbe wọn mì
pọ̀ pẹlu Kora, nigbati ẹgbẹ na fi kú, ni-
gbati iná fi run awọn ãdọtalerugba ọkọnrin,
ti nwọn si di àmi kan.
11 Ṣugbọn awọn ọmọ Kora kò kú.
12 Awọn ọmọ Simeoni bi idile wọn: ti
Nemueli, idile Nemueli: ti Jamini, idile
Jamini: ti Jakini, idile Jakini:
13 Ti Sera, idile Sera: ti Ṣaulu, idile
Ṣaulu.
14 Wọnyi ni idile awọn ọmọ Simeoni,
ẹgba mọkanla o le igba.
15 Awọn ọmọ Gadi bi idile wọn: ti Se-
foni, idile Sefoni: ti Haggi, idile Haggi:
ti Ṣuni, idile Ṣuni:
16 Ti Osni, idile Osni: ti Eri, idile
Eri:
17 Ti Arodu, idile Arodu: ti Areli, idile
Areli.
18 Wọnyi ni idile awọn ọmọ Gadi gẹgẹ
bi awọn ti a kà ninu wọn, nwọn jẹ́ ọkẹ
meji o le ẹdẹgbẹta.
19 Awọn ọmọ Juda, ni Eri ati Onani:
ati Eri ati Onani kú ni ilẹ Kenaani.
20 Ati awọn ọmọ Juda gẹgẹ bi idile wọn;
ti Ṣela, idile Ṣela: ti Peresi, idile Peresi:
ti Sera, idile Sera.
21 Awọn ọmọ Peresi; ti Hesroni, idile
Hesroni: ti Hamulu, idile Hamulu.
22 Wọnyi ni idile Juda gẹgẹ bi awọn ti
a kà ninu wọn, nwọn jẹ́ ẹgba mejidilogoji
o le ẹdẹgbẹta.
23 Awọn ọmọ Issakari gẹgẹ bi idile wọn:
ti Tola, idile Tola: ti Pufa, idile Pufa:
24 Ti Jaṣubu, idile Jaṣubu: ti Ṣimroni,
idile Ṣimroni.
25 Wọnyi ni idile Issakari gẹgẹ bi awọn
ti a kà ninu wọn, nwọn jẹ́ ẹgba mejilelọ-
gbọ̀n o le ọdunrun.
26 Awọn ọmọ Sebuluni gẹgẹ bi idile wọn:
ti Seredi, idile Seredi: ti Eloni, idile Eloni:
ti Jaleeli, idile Jaleeli.
27 Wọnyi ni idile awọn ọmọ Sebuluni
gẹgẹ bi awọn ti a kà ninu wọn, nwọn jẹ́
ọkẹ mẹta o le ẹdẹgbẹta.
28 Awọn ọmọ Josefu gẹgẹ bi idile wọn:
Manasse ati Efraimu.
29 Awọn ọmọ Manasse: ti Makiri, idile
Makiri: Makiri si bi Gileadi: ti Gileadi,
idile awọn ọmọ Gileadi.
30 Wọnyi li awọn ọmọ Gileadi: ti
Ieseri, idile Ieseri: ti Heleki, idile Heleki:
31 Ati ti Asrieli, idile Asrieli: ati ti
Ṣekemu, idile Ṣekemu:
32 Ati Ṣemida, idile awọn ọmọ Ṣemida:
ati ti Heferi, idile awọn ọmọ Heferi.
33 Selofehadi ọmọ Heferi kò si lí ọmọ-

Digitized by Google

kọnrin, bikoṣe ọmọbirin : orukọ awọn ọmọbirin Selofehadi a ma jẹ Mala, ati Noa, ati Hogla, Milka, ati Tirsa.

34 Wọnyi ni idile Manasse, ati awọn ti a kà ninu wọn jẹ́ ẹgba mẹrindilọgbọn o le ẹdẹgbẹrin.

35 Wọnyi li awọn ọmọ Efraimu gẹgẹ bi idile wọn : ti Ṣutela, idile awọn ọmọ Ṣutela : ti Bekeri, idile awọn ọmọ Bekeri : ti Tahani, idile awọn ọmọ Tahani.

36 Wọnyi li awọn ọmọ Ṣutela : ti Erani, idile awọn ọmọ Erani.

37 Wọnyi ni idile awọn ọmọ Efraimu gẹgẹ bi awọn ti a kà ninu wọn, nwọn jẹ́ ẹgba mẹrindilogun o le ẹdẹgbẹta. Wọnyi li awọn ọmọ Josefu gẹgẹ bi idile wọn.

38 Awọn ọmọ Benjamini gẹgẹ bi idile wọn : ti Bela, idile awọn ọmọ Bela : ti Aṣbeli, idile awọn ọmọ Aṣbeli : ti Ahiramu, idile awọn ọmọ Ahiramu.

39 Ti Ṣefufamu, idile awọn ọmọ Ṣufamu : ti Hufamu, idile awọn ọmọ Hufamu.

40 Awọn ọmọ Bela si ni Ardi ati Naamani : ti Ardi, idile awọn ọmọ Ardi : ati ti Naamani, idile awọn ọmọ Naamani.

41 Wọnyi li awọn ọmọ Benjamini gẹgẹ bi idile wọn : ati awọn ti a kà ninu wọn jẹ́ ẹgba mejilelogun o le ẹgbẹjọ.

42 Wọnyi li awọn ọmọ Dani gẹgẹ bi idile wọn : ti Ṣuhamu, idile awọn ọmọ Ṣuhamu. Wọnyi ni idile Dani gẹgẹ bi idile wọn.

43 Gbogbo idile awọn ọmọ Ṣuhamu, gẹgẹ bi awọn ti a kà ninu wọn, nwọn jẹ́ ẹgba mejilelọgbọn o le irinwo.

44 Ti awọn ọmọ Aṣeri gẹgẹ bi idile wọn : ti Imna, idile awọn ọmọ Imna : ti Iṣfi, idile awọn ọmọ Iṣfi : ti Beria, idile awọn ọmọ Beria.

45 Ti awọn ọmọ Beria : ti Heberi, idile awọn ọmọ Heberi : ti Malkieli, idile awọn ọmọ Malkieli.

46 Orukọ ọmọ Aṣeri obirin a si ma jẹ́ Sera.

47 Wọnyi ni idile awọn ọmọ Aṣeri gẹgẹ bi awọn ti a kà ninu wọn ; nwọn jẹ́ ẹgba mẹrindilọgbọn o le egbeje.

48 Ti awọn ọmọ Naftali gẹgẹ bi idile wọn : ti Jaseeli, idile awọn ọmọ Jaseeli : ti Guni, idile awọn ọmọ Guni :

49 Ti Jeseri, idile awọn ọmọ Jeseri : ti Ṣillemu, idile awọn ọmọ Ṣillemu.

50 Wọnyi ni idile ti Naftali gẹgẹ bi idile wọn : awọn ti a si kà ninu wọn jẹ́ ẹgba mejilelogun o le egbeje.

51 Wọnyi li a kà ninu awọn ọmọ Israeli, ọgbọn ọkẹ, o le ẹgbẹsan o din ãdọrin.

52 OLUWA si sọ fun Mose pe,

53 Fun awọn wọnyi ni ki a pín ilẹ na ni iní gẹgẹ bi iye orukọ.

54 Fun awọn ti o pọ̀ ni ki iwọ ki o fi ilẹ-iní pupọ̀ fun, ati fun awọn ti a kére ni ki iwọ ki o fi diẹ fun : ki a fi ilẹ-iní olukuluku fun u gẹgẹ bi iye awọn ti a kà ninu rẹ̀.

55 Ṣugbọn kèké li a o fi pín ilẹ na : gẹgẹ bi orukọ ẹ̀ya awọn baba wọn ni ki nwọn ki o ní i.

56 Gẹgẹ bi kèké ni ki a pín ilẹ-iní na lãrin awọn pupọ̀ ati diẹ.

57 Wọnyi si li awọn ti a kà ninu awọn ọmọ Lefi, gẹgẹ bi idile wọn : ti Gerṣoni, idile awọn ọmọ Gerṣoni : ti Kohati, idile awọn ọmọ Kohati : ti Merari, idile awọn ọmọ Merari.

58 Wọnyi ni idile awọn ọmọ Lefi : idile awọn ọmọ Libni, idile awọn ọmọ Hebroni, idile awọn ọmọ Mali, idile awọn ọmọ Muṣi, idile awọn ọmọ Kora. Kohati si bi Amramu.

59 Orukọ aya Amramu a si ma jẹ́ Jokebedi, ọmọbirin Lefi, ti iya rẹ̀ bi fun Lefi ni Egipti : on si bi Aaroni, ati Mose, ati Miriamu arabirin wọn fun Amramu.

60 Ati fun Aaroni li a bi Nadabu ati Abihu, Eleasari ati Itamari.

61 Ati Nadabu ati Abihu kú, nigbati nwọn mú iná ajeji wá siwaju OLUWA.

62 Awọn ti a si kà ninu wọn jẹ́ ẹgba mọkanla o le ẹgbẹrun, gbogbo awọn ọkọnrin lati ọmọ oṣù kan ati jù bẹ̃ lọ : nitoripe a kò kà wọn kún awọn ọmọ Israeli, nitoriti a kò fi ilẹ-iní fun wọn ninu awọn ọmọ Israeli.

63 Wọnyi li awọn ti a kà lati ọwọ́ Mose ati Eleasari alufa wá, awọn ẹniti o kà awọn ọmọ Israeli ni pẹtẹlẹ̀ Moabu lẹba Jordani leti Jeriko.

64 Ṣugbọn ninu wọnyi kò si ọkọnrin kan ninu awọn ti Mose ati Aaroni alufa kà, nigbati nwọn kà awọn ọmọ Israeli li aginjù Sinai.

65 Nitoriti OLUWA ti wi fun wọn pe, Kíku ni nwọn o kú li aginjù. Kò si kù ọkọnrin kan ninu wọn, bikoṣe Kalebu ọmọ Jefunne, ati Joṣua ọmọ Nuni.

## ORI 27.

NIGBANA ni awọn ọmọbirin Selofehadi, ọmọ Heferi ọmọ Gileadi, ọmọ Makiri, ọmọ Manasse, ti idile Manasse ọmọ Josefu wá : wọnyi si li orukọ awọn ọmọbirin rẹ̀ ; Mala, Noa, ati Hogla, ati Milka, ati Tirsa.

2 Nwọn si duro niwaju Mose, ati niwaju

Digitized by Google

Eleasari alufa, ati niwaju awọn olori ati
gbogbo ijọ, li ẹnu-ọna agọ ajọ wipe,
3 Baba wa kú li aginjù, on kò si sí ninu
ẹgbẹ awọn ti o kó ara wọn jọ pọ̀ si OLUWA
ninu ẹgbẹ Kora: ṣugbọn o kú ninu ẹ̀ṣẹ ara
rẹ̀; kò si lí ọmọkọnrin.
4 Ẽhaṣe ti orukọ baba wa yio fi parẹ
kuro ninu idile rẹ̀, nitoriti kò lí ọmọkọnrin?
Fun wa ni ilẹ-iní lãrin awọn arakọnrin baba
wa.
5 Mose si mú ọ̀ran wọn wá siwaju OLUWA.
6 OLUWA si sọ fun Mose pe,
7 Awọn ọmọbirin Selofehadi sọ rere: ni-
tõtọ, fun wọn ni ilẹ-iní kan lãrin awọn ara-
kọnrin baba wọn; ki iwọ ki o si ṣe ki ilẹ-iní
baba wọn ki o kọja sọdọ wọn.
8 Ki iwọ ki o si sọ fun awọn ọmọ Israeli
pe, Bi ọkọnrin kan ba kú, ti kò si lí ọmọ-
kọnrin, njẹ ki ẹnyin ki o ṣe ki ilẹ-iní rẹ̀ ki
o kọja sọdọ ọmọbirin rẹ̀.
9 Bi on kò ba si lí ọmọbirin, njẹ ki ẹnyin
ki o fi ilẹ-ini rẹ̀ fun awọn arakọnrin rẹ̀.
10 Bi on kò ba si lí arakọnrin, njẹ ki
ẹnyin ki o fi ilẹ-iní rẹ̀ fun awọn arakọnrin
baba rẹ̀:
11 Bi baba rẹ̀ kò ba si lí arakọnrin, njẹ ki
ẹnyin ki o fi ilẹ-iní rẹ̀ fun ibatan rẹ̀, ti o
sunmọ ọ ni idile rẹ̀, on ni ki o jogún rẹ̀:
yio si jasi ìlana idajọ fun awọn ọmọ Israeli,
gẹgẹ bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose.
12 OLUWA si sọ fun Mose pe, Gùn ori
òke Abarimu yi lọ, ki o si wò ilẹ na ti mo fi
fun awọn ọmọ Israeli.
13 Nigbati iwọ ba ri i tán, a o si kó iwọ
jọ pẹlu awọn enia rẹ, gẹgẹ bi a ti kó Aaroni
arakọnrin rẹ jọ.
14 Nitoriti ẹnyin ṣọ̀tẹ si aṣẹ mi li aginjù
Sini, ni ìja ijọ, lati yà mi simimọ́ ni ibi omi
nì niwaju wọn. (Wọnyi li omi Meriba ni
Kadeṣi li aginjù Sini.)
15 Mose si sọ fun OLUWA pe,
16 Jẹ ki OLUWA, Ọlọrun ẹmi gbogbo
enia, ki o yàn ọkọnrin kan sori ijọ,
17 Ti yio ma ṣaju wọn jade lọ, ti yio si
ma ṣaju wọn wọle wá, ti yio si ma sìn wọn
lọ, ti yio si ma mú wọn bọ̀; ki ijọ enia
OLUWA ki o máṣe dabi agutan ti kò lí oluṣọ.
18 OLUWA si sọ fun Mose pe, Iwọ mú
Joṣua ọmọ Nuni, ọkọnrin ninu ẹniti ẹmi wà,
ki o si fi ọwọ́ rẹ lé e lori;
19 Ki o si mu u duro niwaju Eleasari
alufa, ati niwaju gbogbo ijọ; ki o si fi aṣẹ
fun u li oju wọn.
20 Ki iwọ ki o si fi ninu ọlá rẹ si i lara,
ki gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli ki o le gbà
a gbọ́.
21 Ki on si duro niwaju Eleasari alufa,
ẹniti yio bère fun u nipa idajọ Urimu ni-
waju OLUWA: nipa ọ̀rọ rẹ̀ ni ki nwọn ki o
jade lọ, ati nipa ọ̀rọ rẹ̀ ni ki nwọn ki o
wọle, ati on, ati gbogbo awọn ọmọ Israeli
pẹlu rẹ̀, ani gbogbo ijọ.
22 Mose si ṣe bi OLUWA ti paṣẹ fun u:
o si mú Joṣua, o si mu u duro niwaju Elea-
sari alufa, ati niwaju gbogbo ijọ:
23 O si fi ọwọ́ rẹ̀ lé e lori, o si fi aṣẹ fun
u, bi OLUWA ti wi lati ọwọ́ Mose.

## ORI 28.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Fi aṣẹ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si
wi fun wọn pe, Ọrẹ-ẹbọ mi, ati àkara mi
fun ẹbọ mi ti a fi iná ṣe, fun õrùn didùn si
mi, ni ki ẹnyin ma kiyesi lati mú fun mi
wá li akokò wọn.
3 Ki iwọ ki o si wi fun wọn pe, Eyi li
ẹbọ ti a fi iná ṣe, ti ẹnyin o ma múwa fun
OLUWA, akọ ọdọ-agutan meji ọlọdún kan
alailabùkun li ojojumọ́, fun ẹbọ sisun
igbagbogbo.
4 Ọdọ-agutan kan ni ki iwọ ki o fi rubọ
li owurọ̀, ati ọdọ-agutan keji ni ki iwọ ki o
fi rubọ li aṣalẹ;
5 Ati idamẹwa òṣuwọn efa iyẹfun fun
ẹbọ ohunjijẹ, ti a fi idamẹrin òṣuwọn hini
oróro gigún pò.
6 Ẹbọ sisun igbagbogbo ni, ti a ti lana-
silẹ li òke Sinai fun õrùn didùn, ẹbọ ti a fi
iná ṣe si OLUWA.
7 Ati ẹbọ ohunmimu rẹ̀ ki o jẹ́ idamẹrin
òṣuwọn hini fun ọdọ-agutan kan: ni ibi-
mimọ ni ki iwọ ki o dà ọti lile nì silẹ fun
OLUWA fun ẹbọ ohunmimu.
8 Ọdọ-agutan keji ni ki iwọ ki o fi rubọ
li aṣalẹ: bi ẹbọ ohunjijẹ ti owurọ̀, ati bi
ẹbọ ohunmimu rẹ̀ ni ki iwọ ki o ṣe, ẹbọ ti
a fi iná ṣe, õrùn didùn si OLUWA.
9 Ati li ọjọ́-isimi akọ ọdọ-agutan meji
ọlọdún kan alailabùkun, ati idamẹwa meji
òṣuwọn iyẹfun fun ẹbọ ohunjijẹ, ti a fi oró-
ro pò, ati ẹbọ ohunmimu rẹ̀:
10 Eyi li ẹbọ sisun ọjọjọ́ isimi, pẹlu ẹbọ
sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunmimu rẹ̀.
11 Ati ni ìbẹrẹ òṣu nyin ki ẹnyin ki o ru
ẹbọ sisun kan si OLUWA; ẹgbọrọ akọmalu
meji, ati àgbo kan, akọ ọdọ-agutan meje
ọlọdún kan alailabùkun;
12 Ati idamẹwa mẹta òṣuwọn iyẹfun, ti
a fi oróro pò, fun akọmalu kan, fun ẹbọ
ohunjijẹ; ati idamẹwa meji òṣuwọn iyẹfun,
ti a fi oróro pò, fun àgbo kan, fun ẹbọ
ohunjijẹ:

Digitized by Google

13 Ati idamẹwa òṣuwọn iyẹfun, ti a fi oróro pò, fun ọdọ-agutan kan fun ẹbọ ohunjijẹ; fun ẹbọ sisun õrùn didùn, ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA.

14 Ki ẹbọ ohunmimu wọn ki o jẹ́ àbọ òṣuwọn hini ti ọti-waini fun akọmalu kan, ati idamẹta òṣuwọn hini fun àgbo kan, ati idamẹrin òṣuwọn hini fun ọdọ-agutan kan: eyi li ẹbọ sisun oṣuṣù ni gbogbo oṣù ọdún.

15 A o si fi obukọ kan ru ẹbọ ẹ̀ṣẹ si OLUWA; pẹlu ẹbọ sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunmimu rẹ̀.

16 Ati li ọjọ́ kẹrinla oṣù kini, ni irekọja OLUWA.

17 Ati li ọjọ́ kẹdogun oṣù na yi li ajọ: ni ijọ́ meje ni ki a fi jẹ àkara alaiwu.

18 Li ọjọ́ kini ki apejọ mimọ́ ki o wà; ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹ agbara kan:

19 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o ru ẹbọ kan ti a fi iná ṣe, ẹbọ sisun si OLUWA; ẹgbọrọ akọmalu meji, ati àgbo kan, ati akọ ọdọ-agutan meje ọlọdun kan: ki nwọn ki o jẹ́ alailabùkun fun nyin.

20 Ẹbọ ohunjijẹ wọn, iyẹfun ti a fi oróro pò, idamẹwa mẹta òṣuwọn ni ki ẹnyin ki o múwa fun akọmalu kan, ati idamẹwa meji òṣuwọn fun àgbo na.

21 Ati idamẹwa òṣuwọn ni ki iwọ ki o múwa fun ọdọ-agutan kan, fun gbogbo ọdọ-agutan mejeje;

22 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, lati ṣètutu fun nyin.

23 Ki ẹnyin ki o mú wọnyi wá pẹlu ẹbọ sisun owurọ̀, ti iṣe ti ẹbọ sisun igbagbogbo.

24 Bayi ni ki ẹnyin rubọ li ojọjọ́, jalẹ ni ijọ́ mejeje, onjẹ ẹbọ ti a fi iná ṣe, ti õrùn didùn si OLUWA: ki a ru u pẹlu ẹbọ sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunmimu rẹ̀.

25 Ati ni ijọ́-keje ki ẹnyin ki o ní apejọ mimọ́; ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹ agbara kan.

26 Li ọjọ́ akọ́so pẹlu, nigbati ẹnyin ba mú ẹbọ ohunjijẹ titun wá fun OLUWA, lẹhin ọsẹ̀ nyin wọnni, ki ẹnyin ki o ní apejọ mimọ́; ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹ agbara kan:

27 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o fi ẹgbọrọ akọmalu meji, àgbo kan, akọ ọdọ-agutan meje ọlọdún kan, ru ẹbọ sisun fun õrùn didùn si OLUWA;

28 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, iyẹfun ti a fi oróro pò, idamẹwa mẹta òṣuwọn fun akọmalu kan, ati idamẹwa meji òṣuwọn fun àgbo kan,

29 Ati idamẹwa òṣuwọn fun ọdọ-agutan kan, bẽni fun ọdọ-agutan mejeje;

30 Ati obukọ kan, lati ṣètutu fun nyin.

31 Ki ẹnyin ki o ru wọn pẹlu ẹbọ sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀ (ki nwọn ki o jẹ́ alailabùku fun nyin), ati ẹbo ohunmimu wọn.

## ORI 29.

ATI li oṣù keje, li ọjọ́ kini oṣù na ki ẹnyin ki o ní apejọ mimọ́; ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹ agbara kan: ọjọ́ ifunpe ni fun nyin.

2 Ki ẹnyin ki o si fi ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, ati akọ ọdọ-agutan meje ọlọdún kan alailabùku ru ẹbọ sisun fun õrùn didùn si OLUWA:

3 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, iyẹfun ti a fi oróro pò, idamẹwa mẹta òṣuwọn fun akọmalu kan, ati idamẹwa meji òṣuwọn fun àgbo kan,

4 Ati idamẹwa òṣuwọn fun ọdọ-agutan kan, bẽni fun ọdọ-agutan mejeje:

5 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, lati ṣètutu fun nyin;

6 Pẹlu ẹbọ sisun oṣù, ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ ohunmimu wọn, gẹgẹ bi ìlana wọn, fun õrùn didùn, ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA.

7 Ki ẹnyin ki o si ní apejọ mimọ́ ni ijọ́ kẹwa oṣù keje na yi; ki ẹnyin ki o si pọ́n ọkàn nyin loju; ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹkiṣẹ kan:

8 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o ru ẹbọ sisun si OLUWA fun õrùn didùn; ẹgbọrọ akọmalu kan, àgbo kan, ati akọ ọdọ-agutan meje ọlọdún kan; ki nwọn ki o si jẹ́ alailabùku fun nyin:

9 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, iyẹfun ti a fi oróro pò, idamẹwa mẹta òṣuwọn fun akọmalu kan, ati idamẹwa meji òṣuwọn fun àgbo kan,

10 Ati idamẹwa òṣuwọn fun ọdọ-agutan kan, bẽni fun ọdọ-agutan mejeje:

11 Obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; pẹlu ẹbọ ẹ̀ṣẹ fun ètutu, ati ẹbọ sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ ohunmimu wọn.

12 Ati ni ijọ́ kẹdogun oṣù keje, ki ẹnyin ki o ní apejọ mimọ́; ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹ agbara kan, ki ẹnyin ki o si ṣe ajọ fun OLUWA ni ijọ́ meje:

13 Ki ẹnyin ki o si ru ẹbọ sisun kan, ẹbọ ti a fi iná ṣe, ti õrùn didùn si OLUWA; ẹgbọrọ akọmalu mẹtala, àgbo meji, ati akọ ọdọ-agutan mẹrinla ọlọdùn kan; ki nwọn ki o jẹ́ alailabùku:

14 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, iyẹfun ti a fi oróro pò, idamẹwa mẹta òṣuwọn fun akọmalu kan, bẽni fun akọmalu mẹtẹtala, ida-

Digitized by Google

mẹwa meji ọ̀ṣuwọn fun àgbo kan, bẹ̃ni fun
àgbo mejeji,
15 Ati idamẹwa ọ̀ṣuwọn fun ọdọ-agutan
kan, bẹ̃ni fun ọdọ-agutan mẹrẹrinla:
16 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; pẹlu ẹbọ
sisun igbagbogbo, ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ
ohunmimu rẹ̀.
17 Ati ní ijọ́ keji ni ki ẹnyin ki o fi
ẹgbọrọ akọmalu mejila, àgbo meji, ọdọ-
agutan mẹrinla ọlọdún kan alailabùku
rubọ:
18 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohun-
mimu wọn fun akọmalu, fun àgbo, ati fun
ọdọ-agutan, ki o jẹ́ bi iye wọn, gẹgẹ bi
ìlana na:
19 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; pẹlu ẹbọ
sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati
ẹbọ ohunmimu wọn.
20 Ati ni ijọ́ kẹta akọmalu mọkanla,
àgbo meji, akọ ọdọ-agutan mẹrinla ọlọdún
kan alailabùku;
21 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohun-
mimu wọn fun akọmalu, fun àgbo, ati fun
ọdọ-agutan, ki o jẹ́ bi iye wọn, gẹgẹ bi
ìlana na:
22 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; pẹlu ẹbọ
sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati
ẹbọ ohunmimu rẹ̀.
23 Ati ni ijọ́ kẹrin akọmalu mẹwa, àgbo
meji, ati ọdọ-agutan mẹrinla ọlọdún kan
alailabùku:
24 Ẹbọ ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohunmimu
wọn fun akọmalu, fun àgbo, ati fun ọdọ-
agutan, ki o jẹ́ bi iye wọn gẹgẹ bi ìlana
na:
25 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; pẹlu ẹbọ
sisun igbagbogbo, ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ
ohunmimu rẹ̀.
26 Ati ni ijọ́ karun akọmalu mẹsan, àgbo
meji, ati akọ ọdọ-agutan mẹrinla ọlọdún kan
alailabùku:
27 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohun-
mimu wọn fun akọmalu, fun àgbo, ati fun
ọdọ-agutan, ki o jẹ́ bi iye wọn, gẹgẹ bi
ìlana na:
28 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ: pẹlu
ẹbọ sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀,
ati ẹbọ ohunmimu rẹ̀.
29 Ati ni ijọ́ kẹfa akọmalu mẹjọ, àgbo
meji, ati akọ ọdọ-agutan mẹrinla ọlọdún
kan alailabùku:
30 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohun-
mimu wọn fun akọmalu, fun àgbo, ati fun
ọdọ-agutan, ki o jẹ́ bi iye wọn, gẹgẹ bi
ìlana na:
31 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; pẹlu ẹbọ
sisun igbagbogbo, ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ
ohunmimu rẹ̀.
32 Ati ni ijọ́ keje akọmalu meje, àgbo
meji, ati akọ ọdọ-agutan mẹrinla ọlọdún
kan alailabùku:
33 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohun-
mimu wọn fun akọmalu, fun àgbo, ati fun
ọdọ-agutan, ki o jẹ́ bi iye wọn, gẹgẹ bi
ìlana na:
34 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; pẹlu ẹbọ
sisun igbagbogbo, ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati ẹbọ
ohunmimu rẹ̀.
35 Ni ijọ́ kẹjọ ki ẹnyin ki o ní ajọ ti o
ni ironu: ẹnyin kò gbọdọ ṣe iṣẹ agbara kan.
36 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o ru ẹbọ sisun,
ẹbọ ti a fi iná ṣe, ti õrùn didùn si OLUWA:
akọmalu kan, àgbo kan, akọ ọdọ-agutan
meje ọlọdún kan alailabùku:
37 Ati ẹbọ ohunjijẹ wọn, ati ẹbọ ohun-
mimu wọn fun akọmalu, fun àgbo, ati fun
ọdọ-agutan, ki o jẹ́ bi iye wọn, gẹgẹ bi
ìlana na:
38 Ati obukọ kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ; pẹlu ẹbọ
sisun igbagbogbo, ati ẹbọ ohunjijẹ rẹ̀, ati
ẹbọ ohunmimu rẹ̀.
39 Ẹbọ wọnyi ni ki ẹnyin ki o ru si
OLUWA li ajọ nyin, pẹlu ẹjẹ́ nyin, ati ẹbọ
ọrẹ-atinuwa nyin, fun ẹbọ sisun nyin, ati
fun ẹbọ ohun mimu nyin, ati fun ẹbọ alafia
nyin.
40 Mose si sọ fun awọn ọmọ Israeli gẹgẹ
bi gbogbo eyiti OLUWA ti fi aṣẹ lelẹ fun
Mose.

## ORI 30.

MOSE si sọ fun awọn olori awọn ẹ̀ya
awọn ọmọ Israeli, wipe, Eyi li ohun
ti OLUWA palaṣẹ.
2 Bi ọkọnrin kan ba jẹ́ ẹjẹ́ fun OLUWA,
tabi ti o ba bura lati fi dè ara rẹ̀ ni ìde, ki
on ki o máṣe bà ọ̀rọ rẹ̀ jẹ; ki on ki o ṣe
gẹgẹ bi gbogbo eyiti o ti ẹnu rẹ̀ jade.
3 Bi obirin kan pẹlu ba si jẹ́ ẹjẹ́ fun
OLUWA, ti o si dè ara rẹ̀ ni ìde, ni ile baba
rẹ̀ ni ìgba ewe rẹ̀;
4 Ti baba rẹ̀ si gbọ́ ẹjẹ́ rẹ̀, ati ìde rẹ̀ ti o
fi dè ara rẹ̀, ti baba rẹ̀ ba si pa ẹnu rẹ̀ mọ́
si i; njẹ ki gbogbo ẹjẹ́ rẹ̀ ki o duro, ati
gbogbo ìde ti o fi dè ara rẹ̀ yio si duro.
5 Ṣugbọn bi baba rẹ̀ ba kọ̀ fun u li ọjọ́
na ti o gbọ́; kò sí ọkan ninu ẹjẹ́ rẹ̀, tabi
ninu ìde ti o fi dè ara rẹ̀, ti yio duro:
OLUWA yio si darijì i, nitoriti baba rẹ̀ kọ̀
fun u.
6 Bi o ba si kúku li ọkọ, nigbati o jẹ́

Digitized by Google

ẹjẹ́, tabi ti o sọ̀rọ kan lati ẹnu rẹ̀ jade, ninu
eyiti o fi dè ara rẹ̀ ni ìde ;
7 Ti ọkọ rẹ̀ si gbọ́, ti o si pa ẹnu rẹ̀ mọ́
si i li ọjọ́ na ti o gbọ́ ; njẹ́ ẹjẹ́ rẹ̀ yio duro,
ìde ti o fi dè ara rẹ̀ yio si duro.
8 Ṣugbọn bi ọkọ rẹ̀ ba kọ̀ fun u li ọjọ́ na
ti o gbọ́ ; njẹ on o mu ẹjẹ́ rẹ̀ ti o jẹ́ ati
ohun ti o ti ẹnu rẹ̀ jade, eyiti o fi dè ara rẹ̀
dasan : OLUWA yio si darijì i.
9 Ṣugbọn gbogbo ẹjẹ́ opó, ati ti obirin
ti a kọ̀silẹ, ti nwọn fi dè ara wọn, yio wà
lọrùn rẹ̀.
10 Bi o ba si jẹjẹ́ ni ile ọkọ rẹ̀, tabi ti o
si fi ibura dè ara rẹ̀ ni ìde,
11 Ti ọkọ rẹ̀ si gbọ́, ti o si pa ẹnu rẹ̀ mọ́
si i, ti kò si kọ̀ fun u : njẹ gbogbo ẹjẹ́ rẹ̀
ni yio duro, ati gbogbo ìde ti o fi dè ara rẹ̀
yio si duro.
12 Ṣugbọn bi ọkọ rẹ̀ ba sọ wọn dasan pata-
pata li ọjọ́ na ti o gbọ́ ; njẹ ohunkohun ti o
ti ẹnu rẹ̀ jade nipasẹ ẹjẹ́ rẹ̀, tabi nipasẹ ìde
ọkàn rẹ̀, ki yio duro : ọkọ rẹ̀ ti sọ wọn
dasan ; OLUWA yio si darijì i.
13 Gbogbo ẹjẹ́ ati ibura ìde lati fi pọ́n
ara loju, ọkọ rẹ̀ li o le mu u duro, o si le sọ
ọ dasan.
14 Ṣugbọn bi ọkọ rẹ̀ ba pa ẹnu rẹ̀ mọ́ si
i patapata lati ọjọ́ dé ọjọ́ ; njẹ o fi mu gbo-
gbo ẹjẹ́ rẹ̀ duro, tabi gbogbo ìde rẹ̀ ti mbẹ
lara rẹ̀ ; o mu wọn duro, nitoriti o pa ẹnu
rẹ̀ mọ si i li ọjọ́ na ti o gbọ́.
15 Ṣugbọn bi o ba sọ wọn dasan, lẹhin
igbati o gbọ́ ; njẹ on ni yio rù ẹ̀ṣẹ obirin
na.
16 Wọnyi ni ìlana ti OLUWA palaṣẹ fun
Mose, lãrin ọkọnrin ati aya rẹ̀, lãrin baba
ati ọmọbirin rẹ̀, ti iṣe ewe ninu ile baba rẹ̀.

## ORI 31.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Gbẹsan awọn ọmọ Israeli lara awọn
ara Midiani : lẹhin eyinì ni a o kó ọ jọ pẹlu
awọn enia rẹ.
3 Mose si sọ fun awọn enia na pe, Ki
ninu nyin ki o hamọra ogun, ki nwọn ki o
si tọ̀ awọn ara Midiani lọ, ki nwọn ki o si
gbẹsan OLUWA lara Midiani.
4 Ninu ẹ̀ya kọkan ẹgbẹrun enia, ni gbo-
gbo ẹ̀ya Israeli, ni ki ẹnyin ki o rán lọ si
ogun na.
5 Bẹ̃ni nwọn si yàn ninu awọn ẹgbẹgbẹ-
run enia Israeli, ẹgbẹrun enia ninu ẹ̀ya
kọkan, ẹgba mẹfa enia ti o hamọra ogun.
6 Mose si rán wọn lọ si ogun na, ẹgbẹrun
enia ninu ẹ̀ya kọkan, awọn ati Finehasi
ọmọ Eleasari alufa si ogun na, ti on ti
ohunèlo ibi-mimọ́, ati ipè wọnni li ọwọ́ rẹ̀
lati fun.
7 Nwọn si bá awọn ara Midiani jà, bi
OLUWA ti paṣẹ fun Mose ; nwọn si pa gbo-
gbo awọn ọkọnrin.
8 Nwọn si pa awọn ọba Midiani, pẹlu
awọn iyokù ti a pa ; eyinì ni Efi, ati Reke-
mu, ati Suru, ati Huri, ati Reba, ọba Midi-
ani marun : Balaamu ọmọ Beoru ni nwọn
si fi idà pa.
9 Awọn ọmọ Israeli si mú gbogbo awọn
obirin Midiani ni igbẹsin, ati awọn ọmọ
kekere wọn, nwọn si kó gbogbo ohunọ̀sin
wọn, ati gbogbo agbo-ẹran wọn, ati gbogbo
ẹrù wọn.
10 Nwọn si fi iná kun gbogbo ilu wọn
ninu eyiti nwọn ngbé, ati gbogbo ibudó
wọn.
11 Nwọn si kó gbogbo ikogun wọn, ati
gbogbo ohun-iní, ati enia ati ẹran.
12 Nwọn si kó igbẹsin, ati ohun-iní, ati
ikogun na wá sọdọ Mose, ati Eleasari alufa,
ati sọdọ ijọ awọn ọmọ Israeli, si ibudó ni
pẹtẹlẹ̀ Moabu, ti mbẹ lẹba Jordani leti
Jeriko.
13 Ati Mose, ati Eleasari alufa, ati gbo-
gbo awọn olori ijọ, jade lọ ipade wọn lẹhin
ibudó.
14 Mose si binu si awọn olori ogun na,
pẹlu awọn balogun ẹgbẹgbẹrun, ati balogun
ọrọrún, ti o ti ogun na bọ̀.
15 Mose si wi fun wọn pe, Ẹ da gbogbo
awọn obirin si ?
16 Kiyesi i, nipasẹ ọ̀rọ Balaamu awọn
wọnyi li o mu awọn ọmọ Israeli dẹṣẹ si
OLUWA niti ọ̀ran Peori, ti àrun si fi wà ninu
ijọ OLUWA.
17 Njẹ nitorina, ẹ pa gbogbo ọkọnrin
ninu awọn ọmọ wẹ́wẹ, ki ẹ si pa gbogbo
awọn obirin ti o ti mọ̀ ọkọnrin nipa ibá
dapọ̀.
18 Ṣugbọn gbogbo awọn ọmọbirin keke-
ké ti nwọn kò mọ̀ ọkọnrin nipa ibá dapọ̀,
ni ki ẹnyin dasi fun ara nyin.
19 Ki ẹnyin ki o si duro lẹhin ibudó ni
ijọ meje : ẹnikẹni ti o ba pa enia, ati ẹni-
kẹni ti o ba farakàn ẹniti a pa, ki ẹnyin si
wẹ̀ ara nyin mọ́, ati ara awọn igbẹsin nyin
ni ijọ́ kẹta, ati ni ijọ́ keje.
20 Ki ẹnyin si fọ̀ gbogbo aṣọ nyin mọ́,
ati gbogbo ohun ti a fi awọ ṣe, ati ohun
gbogbo iṣẹ irun ewurẹ, ati ohun gbogbo ti
a fi igi ṣe.
21 Eleasari alufa si wi fun awọn ologun
ti nwọn lọ si ogun na pe, Eyi ni ìlana ofin
ti OLUWA filelẹ li aṣẹ fun Mose.

Digitized by Google

22 Kìki wurà, ati fadakà, ati idẹ, ati
irin, ati tangauran, ati ojé,
23 Gbogbo ohun ti o le kọja ninu iná, ni
ki ẹnyin ki o mu là iná já yio si di mimọ́ ;
ṣugbọn a o fi omi ìyasapakan wẹ̀ ẹ mọ́ : ati
gbogbo ohun ti kò le kọja ninu iná ni ki a
mu là inu omi.
24 Ki ẹnyin ki o si fọ̀ aṣọ nyin ni ijọ́
keje, ẹnyin o si di mimọ́, lẹhin eyinì li
ẹnyin o si wá sinu ibudó.
25 OLUWA si sọ fun Mose pe,
26 Kà iye ikogun ti a kó, ti enia ati ti
ẹran, iwọ, ati Eleasari alufa, ati awọn olori
ile baba ijọ :
27 Ki o si pín ikogun na si ipa meji ;
lãrin awọn ologun, ti o jade lọ si ogun na,
ati lãrin gbogbo ijọ.
28 Ki o si gbà ohun idá ti OLUWA lọwọ
awọn ologun ti nwọn jade lọ si ogun na :
ọkan ninu ẹdẹgbẹta, ninu awọn enia, ati
ninu malu, ati ninu kẹtẹkẹtẹ, ati ninu
agbo-ẹran :
29 Gbà a ninu àbọ ti wọn, ki o si fi i fun
Eleasari alufa, fun ẹbọ igbesọsoke OLUWA.
30 Ati ninu àbọ ti iṣe ti awọn ọmọ Israeli,
ki iwọ ki o si gbà ipín kan ninu ãdọta,
ninu enia, ninu malu, ninu kẹtẹkẹtẹ, ati
ninu agbo-ẹran, ninu onirũru ẹran, ki o si
fi wọn fun awọn ọmọ Lefi, ti nṣe itọju agọ́
OLUWA.
31 Ati Mose ati Eleasari alufa si ṣe bi
OLUWA ti paṣẹ fun Mose.
32 Ati ikogun ti o kù ninu ohun-iní ti
awọn ologun kó, o jẹ́ ọkẹ mẹrinlelọgbọ̀n o
din ẹgbẹdọgbọ̀n agutan,
33 Ẹgba mẹrindilogoji malu,
34 Ọkẹ mẹta o le ẹgbẹrun kẹtẹkẹtẹ,
35 Ati enia ninu awọn obirin ti kò mọ̀
ọkọnrin nipa ibá dàpọ, gbogbo wọn jẹ́ ẹgba
mẹrindilogun.
36 Ati àbọ ti iṣe ipín ti awọn ti o jade lọ
si ogun, o jẹ́ ẹgba mejidilãdọsan o le ẹdẹgbẹjọ
agutan ni iye :
37 Idá ti OLUWA ninu agutan wọnni jẹ́
ẹdẹgbẹrin o din mẹdọgbọ̀n.
38 Ati malu jẹ́ ẹgba mejidilogun ; ninu
eyiti idá ti OLUWA jẹ mejilelãdọrin.
39 Kẹtẹkẹtẹ si jẹ́ ẹgba mẹdogun o le
ẹdẹgbẹta ; ninu eyiti idá ti OLUWA jẹ́ ọgọta
o le ọkan.
40 Awọn enia si jẹ́ ẹgba mẹjọ ; ninu eyiti
idá ti OLUWA jẹ́ ọgbọ̀n o le meji.
41 Mose si fi idá ti ẹbọ igbesọsoke OLUWA
fun Eleasari alufa, bi OLUWA ti paṣẹ
fun Mose.
42 Ati ninu àbọ ti awọn ọmọ Israeli, ti
Mose pín kuro ninu ti awọn ọkọnrin ti o
jagun na,
43 (Njẹ àbọ ti ijọ jẹ́ ẹgba mejidilãdọsan
o le ẹdẹgbẹjọ agutan,
44 Ati ẹgba mejidilogun malu.
45 Ati ẹgba mẹdogun o le ẹdẹgbẹta kẹtẹkẹtẹ.
46 Ati ẹgba mẹjọ enia ;)
47 Ani ninu àbọ ti awọn ọmọ Israeli,
Mose mú ipín kan ninu ãdọta, ati ti enia
ati ti eran, o si fi wọn fun awọn ọmọ Lefi,
ti nṣe itọju agọ́ OLUWA ; bi OLUWA ti paṣẹ
fun Mose.
48 Ati awọn olori ti o wà lori ẹgbẹgbẹrun
ogun na, ati awọn balogun ẹgbẹgbẹrun, ati
awọn balogun ọrọrún wá sọdọ Mose :
49 Nwọn si wi fun Mose pe, Awọn iranṣẹ
rẹ ti kà iye awọn ologun, ti mbẹ ni
itọju wa, ọkọnrin kan ninu wa kò si din.
50 Nitorina li awa ṣe mú ọrẹ-ebọ wá fun
OLUWA, ohunkohun ti olukuluku ri, ohun
ọ̀ṣọ wurà, ẹ̀wọn, ati jufù, ati oruka-àmi, ati
oruka-etí, ati ìlẹkẹ, lati fi ṣètutu fun ọkàn
wa niwaju OLUWA.
51 Mose ati Eleasari alufa si gbà wurà
na lọwọ wọn, ani gbogbo ohun-iṣẹ ọṣọ́.
52 Ati gbogbo wurà ẹbọ igbesọsoke ti
nwọn múwa fun OLUWA, lati ọdọ awọn
balogun ẹgbẹgbẹrun, ati lati ọdọ awọn balogun
ọrọrún, o jẹ́ ẹgba mẹjọ o le ẹdẹgbẹrin
o le ãdọta ṣekeli.
53 (Nitoripe awọn ologun ti kó ẹrù, olukuluku
fun ara rẹ̀.)
54 Mose ati Eleasari alufa si gbà wurà
na lọwọ awọn balogun ẹgbẹgbẹrun, ati lọwọ
awọn balogun ọrọrún, nwọn si mú u wá
sinu agọ́ ajọ, ni iranti fun awọn ọmọ Israeli
niwaju OLUWA.

ORI 32.

NJẸ awọn ọmọ Reubeni ati awọn ọmọ
Gadi ní ọ̀pọ̀lọpọ ohunọ̀sin : nwọn si
ri ilẹ Jaseri, ati ilẹ Gileadi, si kiyesi i, ibẹ̀
na, ibi ohunọ̀sin ni ;
2 Awọn ọmọ Gadi ati awọn ọmọ Reubeni
si wá, nwọn si sọ fun Mose, ati fun Eleasari
alufa ati fun awọn olori ijọ pe,
3 Atarotu, ati Diboni, ati Jaseri, ati
Nimra, ati Hešboni, ati Eleale, ati Ṣebamu,
ati Nebo, ati Beoni.
4 Ilẹ na ti OLUWA ti kọlù niwaju ijọ
Israeli, ilẹ ohunọ̀sin ni, awa iranṣẹ rẹ si ní
ohunọ̀sin.
5 Nwọn si wipe, Bi awa ba ri ore-ọfẹ li
oju rẹ, jẹ ki a fi ilẹ yi fun awọn iranṣẹ rẹ

Digitized by Google

fun ilẹ-iní; ki o má si ṣe mú wa gòke
Jordani lọ.
6 Mose si wi fun awọn ọmọ Gadi ati fun
awọn ọmọ Reubeni pe, Awọn arakọnrin
nyin yio ha lọ si ogun, ki ẹnyin ki o si
joko nihinyi?
7 Ẽṣe ti ẹnyin fi ntán ọkàn awọn ọmọ
Israeli niyanju ati rekọja lọ sinu ilẹ ti
OLUWA fi fun wọn?
8 Bẽli awọn baba nyin ṣe, nigbati mo rán
wọn lati Kadeṣi-barnea lọ lati wò ilẹ na.
9 Nitoripe nigbati nwọn gòke lọ dé afoni-
foji Eṣkolu, ti nwon si ri ilẹ na, nwọn tán
ọkàn awọn ọmọ Israeli niyanju, ki nwọn ki
o má le lọ sinu ilẹ ti OLUWA ti fi fun wọn.
10 Ibinu Ọlọrun si rú si wọn nigbana, o
si bura, wipe,
11 Nitõtọ ọkan ninu awọn ọkọnrin wọnyi
ti o gòke lati Egipti wá, lati ẹni ogún ọdún
lọ ati jù bẽ lọ, ki yio ri ilẹ na ti mo ti bura
fun Abrahamu, fun Isaaki, ati fun Jakobu:
nitoriti nwọn kò tẹle mi lẹhin patapata.
12 Bikoṣe Kalebu ọmọ Jefunne ọmọ Ke-
nissi, ati Joṣua ọmọ Nuni: nitoripe awọn
li o tẹle OLUWA lẹhin patapata.
13 Ibinu OLUWA si rú si Israeli, o si mu
wọn rìn kiri li aginjù li ogoji ọdún, titi
gbogbo iran na, ti o ṣe buburu li oju OLUWA
fi run.
14 Si kiyesi i, ẹnyin dide ni ipò baba
nyin, iran ẹlẹṣẹ, lati mu ibinu gbigbona
OLUWA pọ̀ si i si Israeli.
15 Nitoripe bi ẹnyin ba yipada kuro lẹ-
hin rẹ̀, on o si tun fi wọn silẹ li aginjù;
ẹnyin o si run gbogbo awọn enia yi.
16 Nwọn si sunmọ ọ wipe, Awa o kọ́ ile-
ẹran nihinyi fun ohunọ̀sin wa, ati ilu fun
awọn ọmọ wẹ́wẹ wa:
17 Ṣugbọn awa tikala wa yio di ihamọra
wa giri, niwaju awọn ọmọ Israeli, titi awa
o fi mú wọn dé ipò wọn: awọn ọmọ wẹ́wẹ
wa yio si ma gbé inu ilu olodi nitori awọn
ara ilẹ na.
18 Awa ki yio pada bọ̀ si ile wa, titi olu-
kuluku awọn ọmọ Israeli yio fi ní ilẹ-iní rẹ̀.
19 Nitoripe awa ki yio ní ilẹ-iní pẹlu
wọn ni ìha ọhún Jordani, tabi niwaju: ni-
toriti awa ní ilẹ-iní wa ni ìha ihin Jordani
ni ìha ìla õrùn.
20 Mose si wi fun wọn pe, Bi ẹnyin o ba
ṣe eyi; bi ẹnyin o ba di ihamọra niwaju
OLUWA lọ si ogun,
21 Bi gbogbo nyin yio ba gòke Jordani
ni ihamọra niwaju OLUWA, titi yio fi lé
awọn ọtá rẹ̀ kuro niwaju rẹ̀.
22 Ti a o si fi ṣẹ́ ilẹ na niwaju OLUWA:
lẹhin na li ẹnyin o pada, ẹnyin o si jẹ́ àlai-
lẹṣẹ niwaju OLUWA, ati niwaju Israeli; ilẹ
yi yio si ma jẹ́ iní nyin niwaju OLUWA.
23 Ṣugbọn bi ẹnyin ki yio ba ṣe bẽ, ki-
yesi i, ẹnyin dẹṣẹ OLUWA, ki o si dá nyin
loju pe, ẹ̀ṣẹ nyin yio fi nyin hàn.
24 Ẹ kọ́ ilu fun awọn ọmọ wẹ́wẹ nyin,
ati agbo fun agutan nyin; ki ẹ si ṣe eyiti
o ti ẹnu nyin jade wa.
25 Awọn ọmọ Gadi, ati awọn Reubeni si
sọ fun Mose pe, Awọn iranṣẹ rẹ yio ṣe bi
oluwa mi ti fi aṣẹ lelẹ.
26 Awọn ọmọ wẹ́wẹ wa, ati awọn aya
wa, agbo-ẹran wa, ati gbogbo ohunọsìn wa
yio wà nibẹ̀ni ilu Gileadi:
27 Ṣugbọn awọn iranṣẹ rẹ yio gòke odò,
olukuluku ni ihamọra ogun, niwaju OLUWA
lati jà, bi oluwa mi ti wi.
28 Mose si paṣẹ fun Eleasari alufa, ati
fun Joṣua ọmọ Nuni, ati fun awọn olori
ile baba awọn ẹ̀ya ọmọ Israeli, nipa ti wọn.
29 Mose si wi fun wọn pe, Bi awọn ọmọ
Gadi ati awọn ọmọ Reubeni yio ba bá nyin
gòke Jordani lọ olukuluku ni ihamọra fun
ogun, niwaju OLUWA, ti a si ṣẹ́ ilẹ na ni-
waju nyin; njẹ ki ẹnyin ki o fi ilẹ Gileadi
fun wọn ni iní:
30 Ṣugbọn bi nwọn kò ba fẹ́ ba nyin
gòke odò ni ihamọra, njẹ ki nwọn ki o ní
iní lãrin nyin ni ilẹ Kenaani.
31 Ati awọn ọmọ Gadi ati awọn ọmọ
Reubeni dahùn, wipe, Bi OLUWA ti wi fun
awọn iranṣẹ rẹ, bẽli awa o ṣe.
32 Awa o gòke lọ ni ihamọra niwaju
OLUWA si ilẹ Kenaani, ki iní wa ni ìha ihin
Jordani ki o le jẹ́ ti wa.
33 Mose si fi ilẹ-ọba Sihoni ọba awọn ọmọ
Amori, ati ilẹ-ọba Ogu ọba Baṣani fun wọn,
ani fun awọn ọmọ Gadi, ati fun awọn ọmọ
Reubeni, ati fun àbọ ẹ̀ya Manasse ọmọ
Josefu, ilẹ na, pẹlu ilu rẹ̀ li àgbegbe rẹ̀,
ani ilu ilẹ na yiká.
34 Awọn ọmọ Gadi si kọ́ Didoni, ati
Atarotu, ati Aroeri;
35 Ati Atrotu-ṣofani, ati Jaseri, ati
Jogbeha;
36 Ati Beti-nimra, ati Beti-harani, ilu
olodi, ati agbo fun agutan.
37 Awọn ọmọ Reubeni si kọ́ Heṣboni,
ati Eleale, ati Kiriataimu.
38 Ati Nebo, ati Baali-meoni, (nwon pàrọ
orukọ wọn,) ati Sibma: nwọn si sọ ilu ti
nwọn kọ́ li orukọ miran.
39 Awọn ọmọ Makiri ọmọ Manasse si lọ
si Gileadi, nwọn si gbà a, nwọn si lé awọn
ọmọ Amori ti o wà ninu rẹ̀.

Digitized by Google

40 Mose si fi Gileadi fun Makiri ọmọ
Manasse; o si joko ninu rẹ̀.
41 Jairi ọmọ Manasse si lọ, o si gbà
awọn ilu wọn, o si sọ wọn ni Haffotujairi.
42 Noba si lọ, o si gbà Kenati, ati awọn
ileto rẹ̀, o si sọ ọ ni Noba, nipa orukọ ara
rẹ̀.

## ORI 33.

WỌNYI ni ìrin awọn ọmọ Israeli, ti o ti
ilẹ Egipti jade wá pẹlu awọn ogun
wọn, nipa ọwọ́ Mose ati Aaroni.
2 Mose si kọwe ijadelọ wọn gẹgẹ bi ìrin
wọn, nipa aṣẹ OLUWA; wọnyi si ni ìrin
wọn gẹgẹ bi ijadelọ wọn.
3 Nwọn si ṣí kuro ni Ramesesi li oṣù
kini, ni ijọ́ kẹdogun oṣù kini na; ni ijọ́
keji ajọ irekọja li awọn ọmọ Israeli jade
pẹlu ọwọ́ giga li oju gbogbo awọn ara
Egipti.
4 Bi awọn ara Egipti ti nsinkú gbogbo
awọn akọ́bi wọn ti OLUWA kọlù ninu wọn:
lara awọn oriṣa wọn pẹlu li OLUWA ṣe
idajọ.
5 Awọn ọmọ Israeli si ṣí kuro ni Rame-
sesi, nwọn si dó si Sukkotu.
6 Nwọn si ṣí kuro ni Sukkotu, nwọn si
dó si Etamu, ti mbẹ leti aginjù.
7 Nwọn si ṣí kuro ni Etamu, nwọn si
pada lọ si Pi-hahirotu, ti mbẹ niwaju Baali-
sefoni: nwọn si dó siwaju Migdolu.
8 Nwọn si ṣí kuro niwaju Hahirotu,
nwọn si là ãrin okun já lọ si aginjù: nwọn
si rìn ìrin ijọ́ mẹta li aginjù Etamu, nwọn
si dó si Mara.
9 Nwọn si ṣí kuro ni Mara, nwọn si wá
si Elimu: ni Elimu ni orisun omi mejila,
ati ãdọrĩn igi ọpẹ wà; nwọn si dó sibẹ̀.
10 Nwọn si ṣí kuro ni Elimu, nwọn si dó
si ẹba Okun Pupa.
11 Nwọn si ṣí kuro li Okun Pupa, nwọn
si dó si aginjù Sini.
12 Nwọn si ṣí kuro ni aginjù Sini, nwọn
si dó si Dofka.
13 Nwọn si ṣí kuro ni Dofka, nwọn si
dó si Aluṣi.
14 Nwọn si ṣí kuro ni Aluṣi, nwọn si dó
si Refidimu, nibiti omi kò gbé sí fun awọn
enia na lati mu.
15 Nwọn si ṣí kuro ni Refidimu, nwọn
si dó si aginjù Sinai.
16 Nwọn si ṣí kuro ni aginjù Sinai,
nwọn si dó si Kibrotu-hattaafa.
17 Nwọn si ṣí kuro ni Kibrotu-hattaafa,
nwọn si dó si Haserotu.
18 Nwọn si ṣí kuro ni Haserotu, nwọn si
dó si Ritma.
19 Nwọn si ṣí kuro ni Ritma, nwọn si
dó si Rimmon-peresi.
20 Nwọn si ṣí kuro ni Rimmon-peresi,
nwọn si dó si Libna.
21 Nwọn si ṣí kuro ni Libna, nwọn si dó
si Rissa.
22 Nwọn si ṣí kuro ni Rissa, nwọn si dó
si Kehelata.
23 Nwọn si ṣí kuro ni Kehelata, nwọn si
dó si òke Ṣeferi.
24 Nwọn si ṣí kuro ni òke Ṣeferi, nwọn
si dó si Harada.
25 Nwọn si ṣí kuro ni Harada, nwọn si
dó si Makhelotu.
26 Nwọn si ṣí kuro ni Makhelotu, nwọn
si dó si Tahati.
27 Nwọn si ṣí kuro ni Tahati, nwọn si
dó si Tera,
28 Nwọn si ṣí kuro ni Tera, nwọn si dó
si Mitka.
29 Nwọn si ṣí kuro ni Mitka, nwọn si
dó si Haṣmona.
30 Nwọn si ṣí kuro ni Haṣmona, nwọn
si dó si Moserotu.
31 Nwọn si ṣí kuro ni Moserotu, nwọn
si dó si Bene-jaakani.
32 Nwọn si ṣí kuro ni Bene-jaakani,
nwọn si dó si Hori-haggidgadi.
33 Nwọn si ṣí kuro ni Hori-haggidgadi,
nwọn si dó si Jotbata.
34 Nwọn si ṣí kuro ni Jotbata, nwọn si
dó si Abrona.
35 Nwọn si ṣí kuro ni Abrona, nwọn si
dó si Esion-geberi.
36 Nwọn si ṣí kuro ni Esion-geberi,
nwọn si dó si aginjù Sini, (ti iṣe Kade-
ṣi,)
37 Nwọn si ṣí kuro ni Kadeṣi, nwọn si
dó si òke Hori, leti ilẹ Edomu.
38 Aaroni alufa si gùn òke Hori lọ nipa
aṣẹ OLUWA, o si kú nibẹ̀, li ogoji ọdún lẹhin
ti awọn ọmọ Israeli ti ilẹ Egipti jade wá,
li ọjọ́ kini oṣù karun.
39 Aaroni si jẹ́ ẹni ọgọfa ọdún o le mẹta
nigbati o kú li òke Hori.
40 Ara Kenaani, ọba Aradi, ti ngbé ìha
gusù ni ilẹ Kenaani, o gburó pe awọn ọmọ
Israeli mbọ̀.
41 Nwọn si ṣí kuro ni òke Hori, nwọn si
dó si Salmona.
42 Nwọn si ṣí ni Salmona, nwọn si dó si
Punoni.
43 Nwọn si ṣí kuro ni Punoni, nwọn si
dó si Obotu.

Digitized by Google

44 Nwọn si ṣí kuro ni Obotu, nwọn si dó
si Iye-abarimu, li àgbegbe Moabu.
45 Nwọn si ṣí kuro ni Iyimu, nwọn si dó
si Dibon-gadi.
46 Nwọn si ṣí kuro ni Dibon-gadi, nwọn
si dó si Almon-diblataimu.
47 Nwọn si ṣí kuro ni Almon-diblataimu,
nwọn si dó si òke Abarimu, niwaju Nebo.
48 Nwọn si ṣí kuro ni òke Abarimu,
nwọn si dó si pẹtẹlẹ̀ Moabu lẹba Jordani
leti Jeriko.
49 Nwọn si dó si ẹba Jordani, lati Beti-
jeṣimotu titi dé Abeli-ṣittimu ni pẹtẹlẹ̀
Moabu.
50 OLUWA si sọ fun Mose ni pẹtẹlẹ̀ Moa-
bu lẹba Jordani leti Jeriko, wipe,
51 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba gòke odò
Jordani si ilẹ Kenaani:
52 Nigbana ni ki ẹnyin ki o lé gbogbo
awọn ara ilẹ na kuro niwaju nyin; ki ẹnyin
si run gbogbo aworán wọn, ki ẹnyin si run
gbogbo ere didà wọn, ki ẹnyin si wó gbogbo
ibi giga wọn palẹ:
53 Ki ẹnyin ki o si gbà ilẹ na, ki ẹnyin
ki o si ma gbé inu rẹ̀: nitoripe mo ti fi ilẹ
na fun nyin lati ní i.
54 Ki ẹnyin ki o si fi keké pín ilẹ na ni
iní fun awọn idile nyin; fun ọ̀pọ ni ki
ẹnyin ki o fi ilẹ-iní pupọ̀ fun, ati fun diẹ
ni ki ẹnyin ki o fi ilẹ-iní diẹ fun: ki ilẹ-
iní olukuluku ki o jẹ́ ibiti keké rẹ̀ ba bọ́ si;
gẹgẹ bi ẹ̀ya awọn baba nyin ni ki ẹnyin ki
o ní i.
55 Ṣugbọn bi ẹnyin kò ba lé awọn ara ilẹ
na kuro niwaju nyin; yio si ṣe, awọn ti
ẹnyin jẹ ki o kù ninu wọn yio di ẹgún si
oju nyin, ati ẹgún si nyin ni iha, nwọn o si
ma yọ nyin lẹnu ni ilẹ na, ninu eyiti ẹnyin
ngbé.
56 Yio si ṣe, bi emi ti rò lati ṣe si wọn,
bẹ̃ni emi o ṣe si nyin.

## ORI 34.

OLUWA si sọ fun Mose pe,
2 Fi aṣẹ fun awọn ọmọ Israeli, ki o
si wi fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba dé ilẹ
Kenaani, (eyi ni ilẹ ti yio bọ́ si nyin lọwọ
ni iní, ani ilẹ Kenaani gẹgẹ bi àgbegbe rẹ̀,)
3 Njẹ ki iha gusù nyin ki o jẹ́ ati aginjù
Sini lọ titi dé ẹba Edomu, ati opinlẹ gusù
nyin ki o jẹ́ lati opin Okun Iyọ̀ si iha ila-
õrùn:
4 Ki opinlẹ nyin ki o si yí lati gusù wá
si igoke Akrabbimu, ki o si kọja lọ si Sini:
ati ijadelọ rẹ̀ ki o jẹ́ ati gusù lọ si Kadeṣi-
barnea, ki o si dé Hasari-addari, ki o si
kọja si Asmoni:
5 Ki opinlẹ rẹ̀ ki o si yiká lati Asmoni
lọ dé odò Egipti, okun ni yio si jẹ́ opin rẹ̀.
6 Ati opinlẹ iha iwọ-õrùn, ani okun nla
ni yio jẹ́ opin fun nyin: eyi ni yio jẹ́ opinlẹ
iha iwọ-õrùn fun nyin.
7 Eyi ni yio si jẹ́ opinlẹ iha ariwa fun
nyin: lati okun nla lọ ki ẹnyin ki o fi ori
sọ òke Hori:
8 Lati òke Hori lọ ki ẹnyin ki o fi ori sọ
ati wọ̀ Hamati; ijadelọ opinlẹ na yio si jẹ́
Sedadi:
9 Opinlẹ rẹ yio si dé Sifroni, ati ijadelọ
rẹ̀ yio dé Hasari-enani: eyi ni yio jẹ́ opinlẹ
iha ariwa nyin.
10 Ki ẹnyin ki o si sàmi si opinlẹ nyin
ni iha ila-õrùn lati Hasari-enani lọ dé
Ṣefamu:
11 Ki opinlẹ na ki o si ti Ṣefamu sọkalẹ
lọ si Ribla, ni iha ila-õrun Aini; ki opinlẹ
na ki o si sọkalẹ lọ, ki o si dé iha okun
Kinnereti ni iha ila-õrùn.
12 Ki opinlẹ na ki o si sọkalẹ lọ si Jor-
dani, ijadelọ rẹ̀ yio jẹ Okun Iyọ̀: eyi ni yio
jẹ́ ilẹ nyin gẹgẹ bi àgbegbe rẹ̀ yiká kiri.
13 Mose si paṣẹ fun awọn ọmọ Israeli,
wipe, Eyi ni ilẹ na ti ẹnyin o fi keké gbà
ni iní, ti OLUWA paṣẹ lati fi fun ẹ̀ya mẹsan,
ati àbọ ẹ̀ya nì:
14 Fun ẹ̀ya awọn ọmọ Reubeni gẹgẹ bi
ile baba wọn, ati ẹ̀ya awọn ọmọ Gadi gẹgẹ
bi ile baba wọn ti gbà; àbọ ẹ̀ya Manasse
si ti gbà, ipín wọn:
15 Ẹya mejeji ati àbọ ẹ̀ya nì ti gbà ipín
wọn ni iha ihin Jordani leti Jeriko, ni iha
gabasi, ni iha ila-õrùn.
16 OLUWA si sọ fun Mose pe,
17 Wọnyi li orukọ awọn ọkọnrin ti yio
pín ilẹ na fun nyin: Eleasari alufa, ati
Joṣua ọmọ Nuni.
18 Ki ẹnyin ki o si mú olori kan ninu
ẹ̀ya kọkan, lati pín ilẹ na ni iní.
19 Orukọ awọn ọkọnrin na si ni wọnyi:
ni ẹ̀ya Juda, Kalebu ọmọ Jefunne.
20 Ati ni ẹ̀ya awọn ọmọ Simeoni, Ṣemu-
eli ọmọ Ammihudu.
21 Ni ẹ̀ya Benjamini, Elidadi ọmọ Kis-
loni.
22 Ati olori ẹ̀ya awọn ọmọ Dani, Bukki
ọmọ Jogli.
23 Olori awọn ọmọ Josefu: ni ẹ̀ya awọn
ọmọ Manasse, Hannieli ọmọ Efodu:
24 Ati olori ẹ̀ya awọn ọmọ Efraimu,
Kemueli ọmọ Ṣiftani.

Digitized by Google

25 Ati olori ẹ̀ya awọn ọmọ Sebuluni,
Elisafani ọmọ Parnaki.
26 Ati olori ẹ̀ya awọn ọmọ Issakari,
Paltieli ọmọ Assani.
27 Ati olori ẹ̀ya awọn ọmọ Aṣeri, Ahi-
hudu ọmọ Ṣelomi.
28 Ati olori ẹ̀ya awọn ọmọ Naftali,
Pedaheli ọmọ Ammihudu.
29 Awọn wọnyi li ẹniti OLUWA paṣẹ fun
lati pín iní na fun awọn ọmọ Israeli ni ilẹ
Kenaani.

## ORI 35.

OLUWA si sọ fun Mose ni pẹtẹlẹ̀ Moabu
lẹba Jordani leti Jeriko, wipe,
2 Paṣẹ fun awọn ọmọ Israeli, ki nwọn
ki o fi ilu fun awọn ọmọ Lefi ninu ipín ilẹ-
iní wọn, lati ma gbé; ki ẹnyin ki o si fi
ẹbẹba-ilu fun awọn ọmọ Lefi ni ilu wọnni
yi wọn ká.
3 Ki nwọn ki o ní ilu lati ma gbé; ati
ẹbẹba-ilu wọn fun ohunọ̀sin wọn, ati fun
ohun-iní wọn, ati fun gbogbo ẹran wọn.
4 Ati ẹbẹba-ilu, ti ẹnyin o fi fun awọn
ọmọ Lefi, lati odi ilu lọ sẹhin rẹ̀ ki o jẹ́
ẹgbẹrun igbọnwọ yiká.
5 Ki ẹnyin ki o si wọ̀n lati ẹhin ode ilu
na lọ ni ìha ìla-õrùn ẹgba igbọnwọ, ati ni
ìha gusù ẹgba igbọnwọ, ati ni ìha ìwọ-õrùn
ẹgba igbọnwọ, ati ni ìha ariwa ẹgba igbọn-
wọ; ki ilu na ki o si wà lãrin. Eyi ni
yio si ma ṣe ẹbẹba-ilu fun wọn.
6 Ati ninu ilu ti ẹnyin o fi fun awọn
ọmọ Lefi, mẹfa o jẹ́ ilu àbo, ti ẹnyin o yàn
fun aṣi-enia-pa, ki o le ma salọ sibẹ̀: ki
ẹnyin ki o si fi ilu mejilelogoji kún wọn.
7 Gbogbo ilu ti ẹnyin o fi fun awọn ọmọ
Lefi ki o jẹ́ mejidilãdọta: wọnyi ni ki ẹnyin
fi fun wọn pẹlu ẹbẹba wọn.
8 Ati ilu ti ẹnyin o fi fun wọn, ki o jẹ́
ninu ilẹ-iní awọn ọmọ Israeli, lọwọ ẹniti o
ní pupọ̀ li ẹnyin o gbà pupọ̀; ṣugbọn lọwọ
ẹniti o ní diẹ li ẹnyin o gbà diẹ: ki oluku-
luku ki o fi ninu ilu rẹ̀ fun awọn ọmọ Lefi
gẹgẹ bi ilẹ-iní rẹ̀ ti o ní.
9 OLUWA si sọ fun Mose pe,
10 Sọ fun awọn ọmọ Israeli, ki o si wi
fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba gòke Jordani
lọ si ilẹ Kenaani;
11 Nigbana ni ki ẹnyin ki o yàn ilu fun
ara nyin ti yio jẹ́ ilu àbo fun nyin; ki
apania ti o pa enia li aimọ̀ ki o le ma sa lọ
sibẹ̀.
12 Nwọn o si jasi ilu àbo kuro lọwọ
agbẹsan; ki ẹniti o pa enia ki o má ba
kú titi yio fi duro niwaju ijọ awọn enia ni
idajọ.
13 Ati ninu ilu wọnyi ti ẹnyin o fi fun
wọn, mẹfa yio jẹ́ ilu àbo fun nyin.
14 Ki ẹnyin ki o yàn ilu mẹta ni ìha ihin
Jordani, ki ẹnyin ki o si yàn ilu mẹta ni
ilẹ Kenaani, ti yio ma jẹ́ ilu àbo.
15 Ilu mẹfa wọnyi ni yio ma jẹ́ àbo fun
awọn ọmọ Israeli, ati fun alejò ati fun atipo
lãrin wọn: ki olukuluku ẹniti o ba pa enia
li aimọ̀ ki o le ma salọ sibẹ̀.
16 Ṣugbọn bi o ba fi ohunèlo irin lù u,
ti o si kú, apania li on: pipa li a o pa
apania na.
17 Ati bi o ba sọ okuta lù u, ti o le ti
ipa rẹ̀ kú, ti o si kú, apania li on: a o pa
apania na.
18 Tabi bi o ba fi ohunèlo igi lù u, ti o
le ti ipa rẹ̀ kú, ti o si kú, apania li on: pipa
li a o pa apania na.
19 Agbẹsan ẹ̀jẹ tikalarẹ̀ ni ki o pa apania
na: nigbati o ba bá a, ki o pa a.
20 Ṣugbọn bi o ba ṣepe o fi irira gún u,
tabi ti o ba sọ nkan lù u, lati ibuba wá, ti
on si kú;
21 Tabi bi o nṣe ọtá, ti o fi ọwọ́ rẹ̀ lù u,
ti on si kú: ẹniti o lù u nì pipa li a o pa a;
nitoripe apania li on: agbẹsan ẹ̀jẹ ni ki o
pa apania na, nigbati o ba bá a.
22 Ṣugbọn bi o ba fi nkan gún u lojiji
laiṣe ọtá, tabi ti o sọ ohunkohun lù u laiba
dè e,
23 Tabi okuta kan li o sọ, nipa eyiti enia
le fi kú, ti kò ri i, ti o si sọ ọ lù u, ti on si
kú, ti ki iṣe ọtá rẹ̀, ti kò si wá ibi rẹ̀:
24 Nigbana ni ki ijọ ki o ṣe idajọ lãrin
ẹniti o pa enia ati agbẹsan ẹ̀jẹ na, gẹgẹ bi
idajọ wọnyi:
25 Ki ijọ ki o si gbà ẹniti o pani li ọwọ́
agbẹsan ẹ̀jẹ, ki ijọ ki o si mú u pada lọ si
ilu àbo rẹ̀, nibiti o ti sá si: ki o si ma gbé
ibẹ̀ titi di ìgba ikú olori alufa, ti a fi oróro
mimọ́ yàn.
26 Ṣugbọn bi apania na ba ṣèṣi jade lọ si
opinlẹ ilu àbo rẹ̀, nibiti o ti sá si;
27 Ti agbẹsan ẹ̀jẹ na si ri i lẹhin opinlẹ
ilu àbo rẹ̀, ti agbẹsan ẹ̀jẹ si pa apania na;
on ki yio jẹbi ẹ̀jẹ:
28 Nitoripe on iba jọko ninu ilu àbo rẹ̀
titi di ìgba ikú olori alufa: ati lẹhin ikú
olori alufa ki apania na ki o pada lọ si ilẹ
iní rẹ̀.
29 Ohun wọnyi ni o si jẹ́ ìlana idajọ
fun nyin ni iraniran nyin ni ibujoko nyin
gbogbo.
30 Ẹnikẹni ti o ba pa enia, lati ẹnu

Digitized by Google

awọn ẹlẹri wá li a o pa apania na: ṣugbọn
ẹlẹri kanṣoṣo ki yio jẹri si ẹnikan lati
pa a.
31 Pẹlupẹlu ki ẹnyin ki o máṣe gbà
ohun-irasilẹ fun ẹmi apania, ti o jẹbi ikú:
ṣugbọn pipa ni ki a pa a.
32 Ki ẹnyin ki o má si ṣe gbà ohun-
irasilẹ fun ẹniti o salọ si ilu àbo rẹ̀, pe ki
on ki o tun pada lọ ijoko ni ilẹ na, titi di
ìgba ikú alufa.
33 Ẹnyin kò si gbọdọ bà ilẹ na jẹ́ ninu
eyiti ẹnyin ngbé: nitoripe ẹ̀jẹ ama bà ilẹ
jẹ́: a kò si le ṣètutu fun ilẹ nitori ẹ̀jẹ ti a
ta sinu rẹ̀, bikoṣe nipa ẹ̀jẹ ẹniti o ta a.
34 Iwọ kò si gbọdọ sọ ilẹ na di alaimọ́,
ninu eyiti ẹnyin o joko, ninu eyiti emi
ngbé: nitori Emi JEHOFA ni ngbé inu
awọn ọmọ Israeli.

## ORI 36.

AWỌN baba àgba ti idile awọn ọmọ
Gileadi, ọmọ Makiri, ọmọ Manasse,
ti idile awọn ọmọ Josefu, sunmọtosi, nwọn
si sọ niwaju Mose, ati niwaju awọn olori,
awọn baba àgba awọn ọmọ Israeli:
2 Nwọn si wipe, OLUWA ti paṣẹ fun
oluwa mi lati fi keké pín ilẹ na fun awọn
ọmọ Israeli ni iní: a si fi aṣẹ fun oluwa mi
lati ọdọ OLUWA wá lati fi ilẹ-iní Selofehadi
arakọnrin wa fun awọn ọmọ rẹ̀ obirin.
3 Bi a ba si gbé wọn niyawo fun ẹnikan
ninu awọn ọmọkọnrin ẹ̀ya awọn ọmọ Israeli
miran, nigbana ni a o gbà ilẹ-iní wọn kuro
ninu ilẹ-iní awọn baba wa, a o si fi kún ilẹ-
iní ẹ̀ya ti a gbé wọn si: bẹ̃li a o si gbà a
kuro ninu ipín ilẹ-iní ti wa.
4 Ati nigbati ọdún jubeli awọn ọmọ
Israeli ba dé, nigbana li a o fi ilẹ-iní wọn
kún ilẹ-iní ẹ̀ya ti a gbé wọn si: bẹ̃li a o si
gbà ilẹ-iní wọn kuro ninu ilẹ-iní ẹ̀ya awọn
baba wa.
5 Mose si paṣẹ fun awọn ọmọ Israeli gẹgẹ
bi ọ̀rọ OLUWA, pe, Ẹya awọn ọmọ Josefu
fọ̀ rere.
6 Eyi li ohun ti OLUWA palaṣẹ nipa ti
awọn ọmọbirin Selofehadi, wipe, Ki nwọn
ki o ṣe aya ẹniti o wù wọn; kìki pe, ninu
idile ẹ̀ya baba wọn ni ki nwọn ki o gbe-
yawo si.
7 Bẹ̃ni ilẹ-iní awọn ọmọ Israeli ki yio yi
lati ẹ̀ya de ẹ̀ya: nitori ki olukuluku awọn
ọmọ Israeli ki o le faramọ́ ilẹ-iní ẹ̀ya awọn
baba rẹ̀:
8 Ati gbogbo awọn ọmọbirin, ti o ní ilẹ-
iní ninu ẹ̀ya awọn ọmọ Israeli, ki o ṣe aya
fun ọkan ninu idile ẹ̀ya baba rẹ̀, ki oluku-
luku awọn ọmọ Israeli ki o le ma jogún
ilẹ-iní awọn baba rẹ̀.
9 Bẹ̃ni ki ilẹ-iní ki o máṣe yi lati ẹ̀ya
kan lọ si ẹ̀ya keji; ṣugbọn ki olukuluku
ẹ̀ya awọn ọmọ Israeli ki o faramọ́ ilẹ-iní
tirẹ̀.
10 Bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose, bẹ̃li awọn
ọmọbirin Selofehadi ṣe:
11 Nitoripe a gbé Mala, Tirsa, ati Hogla,
ati Milka, ati Noa, awọn ọmọbirin Selofe-
hadi niyawo fun awọn ọmọ arakọnrin baba
wọn.
12 A si gbé wọn niyawo sinu idile awọn
ọmọ Manasse ọmọ Josefu, ilẹ-ini wọn si
duro ninu ẹ̀ya idile baba wọn.
13 Wọnyi ni aṣẹ ati idajọ ti OLUWA
palaṣẹ fun awọn ọmọ Israeli lati ọwọ́
Mose, ni pẹtẹlẹ̀ Moabu lẹba Jordani leti
Jeriko.

---

IWE KARUN TI MOSE,

TI A NPE NI

# DEUTERONOMI.

## ORI 1.

WỌNYI li ọ̀rọ ti Mose sọ fun gbogbo
Israeli ni ìha ihin Jordani li aginjù,
ni pẹtẹlẹ̀ ti o kọjusi Okun Pupa, li agbede-
meji Parani, ati Tofeli, ati Labani, ati
Haserotu, ati Disahabu.
2 Ijọ́ mọkanla ni lati Horebu wá li ọ̀na
òke Seiri dé Kadeṣi-barnea.
3 O si ṣe nigbati o di ogoji ọdún, li oṣù

Digitized by Google

kọkanla, li ọjọ́ kini oṣù na, ni Mose sọ fun
awọn ọmọ Israeli, gẹgẹ bi gbogbo eyiti
OLUWA ti fun u li aṣẹ fun wọn ;
4 Lẹhin igbati o pa Sihoni tán ọba awọn
ọmọ Amori, ti o ngbé Heṣboni, ati Ogu ọba
Baṣani, ti o ngbé Aṣtarotu, ni Edrei :
5 Ni ìha ihin Jordani, ni ilẹ Moabu, on
ni Mose bẹ̀rẹsi isọ asọye ofin yi, wipe,
6 OLUWA Ọlọrun wa sọ fun wa ni Horebu,
wipe, Ẹ gbé ori òke yi pẹ to :
7 Ẹ yipada, ki ẹnyin si mú ọ̀na nyin pọ̀n,
ki ẹ si lọ si òke awọn ọmọ Amori, ati si
gbogbo àgbegbe rẹ̀, ni pẹtẹlẹ̀, li ori òke, ati
li afonifoji, ati ni ìha gusù, ati leti okun,
si ilẹ awọn ara Kenaani, ati si Lebanoni,
dé odò nla nì, odò Euferate.
8 Wò o, mo ti fi ilẹ na siwaju nyin : ẹ
wọ̀ ọ lọ ki ẹ si gbà ilẹ na ti OLUWA bura
fun awọn baba nyin, fun Abrahamu, fun
Isaaki, ati fun Jakobu, lati fi fun wọn ati
fun irú-ọmọ wọn lẹhin wọn.
9 Mo si sọ fun nyin ni ìgba na pe, Emi
nikan kò le rù ẹrù nyin :
10 OLUWA Ọlọrun nyin ti mu nyin bisi
i, si kiyesi i, li oni ẹnyin dabi irawọ oju-
ọrun fun ọ̀pọ.
11 Ki OLUWA, Ọlọrun awọn baba nyin
ki o fi kún iye nyin ni igba ẹgbẹrun, ki
o si busi i fun nyin, bi o ti ṣe ileri fun
nyin !
12 Emi o ti ṣe le nikan rù inira nyin,
ati ẹrù nyin, ati ìja nyin ?
13 Ẹ mú awọn ọkọnrin ọlọgbọ́n wá, ati
amoye, ati ẹniti a mọ̀ ninu awọn ẹ̀ya nyin,
emi o si fi wọn jẹ́ olori nyin.
14 Ẹnyin si da mi li ohùn, ẹ si wipe,
Ohun ti iwọ sọ nì, o dara lati ṣe.
15 Bẹ̃ni mo mú olori awọn ẹ̀ya nyin,
awọn ọlọgbọ́n ọkọnrin, ẹniti a mọ̀, mo si fi
wọn jẹ́ olori nyin, olori ẹgbẹgbẹrun, ati
olori ọrọrún, ati olori ãradọta, ati olori
mẹwa-mẹwa, ati awọn olori gẹgẹ bi awọn
ẹ̀ya nyin.
16 Mo si fi aṣẹ lelẹ fun awọn onidajọ
nyin nigbana pe, Ẹ ma gbọ́ ẹjọ́ lãrin awọn
arakọnrin nyin, ki ẹ si ma ṣe idajọ ododo
lãrin olukuluku ati arakọnrin rẹ̀, ati alejò
ti mbẹ lọdọ rẹ̀.
17 Ẹ kò gbọdọ ṣe ojusaju ni idajọ ; ẹ gbọ́
ti ewe gẹgẹ bi ti àgba ; ẹ kò gbọdọ bẹ̀ru oju
enia ; nitoripe ti Ọlọrun ni idajọ : ọ̀ran ti
o ba si ṣoro fun nyin, ẹ mú u tọ̀ mi wá, emi
o si gbọ́ ọ.
18 Emi si fi aṣẹ ohun gbogbo ti ẹnyin o
ma ṣe lelẹ fun nyin ni ìgba na.
19 Nigbati awa si kuro ni Horebu, awa
rìn gbogbo aginjù nla nì ti o ni ẹ̀ru já, ti
ẹnyin ri li ọ̀na òke awọn ọmọ Amori, bi
OLUWA Ọlọrun wa ti fun wa li aṣẹ ; awa si
wá si Kadeṣi-barnea.
20 Emi si wi fun nyin pe, Ẹnyin dé òke
awọn ọmọ Amori na, ti OLUWA Ọlọrun wa
fi fun wa.
21 Wò o, OLUWA Ọlọrun rẹ ti fi ilẹ na
siwaju rẹ : gòke lọ, ki o si gbà a, bi OLUWA,
Ọlọrun awọn baba rẹ ti wi fun ọ ; máṣe
bẹ̀ru, bẹ̃ni ki àiya máṣe fò ọ.
22 Gbogbo nyin si tọ̀ mi wá, ẹ si wipe,
Jẹ ki awa ki o rán enia lọ siwaju wa, ki
nwọn ki o si rìn ilẹ na wò fun wa, ki nwọn
ki o si mú ìhin pada tọ̀ wa wá, niti ọ̀na ti
a o ba gòke lọ, ati ti ilu ti a o yọ̀ si.
23 Ọ̀rọ na si dara loju mi : mo si yàn
ọkọnrin mejila ninu nyin, ẹnikan ninu ẹ̀ya
kan :
24 Nwọn si yipada nwọn si lọ sori òke,
nwọn si wá si afonifoji Eṣkolù, nwọn si rìn
ilẹ na wò.
25 Nwọn si mú ninu eso ilẹ na li ọwọ́
wọn, nwọn si mú u sọkalẹ wá fun wa, nwọn
si mú ìhin pada wá fun wa, nwọn si wipe,
Ilẹ ti OLUWA Ọlọrun wa fi fun wa, ilẹ
rere ni.
26 Ṣugbọn ẹnyin kò fẹ́ gòke lọ, ẹnyin si
ṣọ̀tẹ si aṣẹ OLUWA Ọlọrun nyin :
27 Ẹnyin si kùn ninu agọ́ nyin, wipe,
Nitoriti OLUWA korira wa, li o ṣe mú wa
lati Egipti jade wá, lati fi wa lé ọwọ́ awọn
ọmọ Amori, lati run wa.
28 Nibo li awa o gbé gòke lọ ? awọn ara-
kọnrin wa ti daiyafò wa, wipe, Awọn enia
na sigbọnlẹ jù wa lọ ; ilu wọn tobi a si
mọdi wọn kan ọrun : pẹlupẹlu awa ri awọn
ọmọ Anaki nibẹ̀.
29 Nigbana ni mo wi fun nyin pe, Ẹ
máṣe fòya, bẹ̃ni ki ẹ máṣe bẹ̀ru wọn.
30 OLUWA Ọlọrun nyin ti nṣaju nyin, on
ni yio jà fun nyin, gẹgẹ bi gbogbo eyiti o
ṣe fun nyin ni Egipti li oju nyin ;
31 Ati li aginjù, nibiti iwọ ri bi OLUWA
Ọlọrun rẹ ti gbé ọ, bi ọkọnrin ti igbé ọmọ
rẹ̀, li ọ̀na nyin gbogbo ti ẹnyin rìn, titi
ẹnyin fi dé ihinyi.
32 Sibẹ̀ ninu nkan yi ẹnyin kò gbà
OLUWA Ọlọrun nyin gbọ́.
33 Ti nlọ li ọ̀na ṣaju nyin, lati wá ibi
fun nyin, ti ẹnyin o pagọ́ nyin si, ninu iná
li oru, lati fi ọ̀na ti ẹnyin o gbà hàn nyin,
ati ninu awọsanma li ọsán.
34 OLUWA si gbọ́ ohùn ọ̀rọ nyin, o si
binu, o si bura, wipe,
35 Nitõtọ ọkan ninu awọn ọkọnrin wọnyi

Digitized by Google

ti iran buburu yi, ki yio ri ilẹ rere na, ti
mo ti bura lati fi fun awọn baba nyin,
36 Bikoṣe Kalebu ọmọ Jefunne, on ni
yio ri i; on li emi o fi ilẹ na ti o tẹ̀mọlẹ
fun, ati fun awọn ọmọ rẹ̀: nitoriti o tẹle
OLUWA lẹhin patapata.
37 OLUWA si binu si mi pẹlu nitori nyin,
wipe, Iwọ pẹlu ki yio dé ibẹ̀:
38 Joṣua ọmọ Nuni, ti ima duro niwaju
rẹ, on ni o dé ibẹ̀: gbà a ni iyanju; nito-
ripe on ni yio mu Israeli ní i.
39 Ati awọn ọmọ wẹ́wẹ nyin, ti ẹnyin
wipe nwọn o di ijẹ, ati awọn ọmọ nyin, ti
nwọn kò mọ̀ rere tabi buburu loni yi, awọn
ni o dé ibẹ̀, awọn li emi o si fi i fun, awọn
ni yio si ní i.
40 Ṣugbọn bi o ṣe ti nyin ni, ẹ pada, ẹ
mú ọ̀na nyin pọ̀n lọ si aginjù li ọ̀na Okun
Pupa.
41 Nigbana li ẹ dahùn, ẹ si wi fun mi
pe, Awa ti ṣẹ̀ si OLUWA, awa o gòke lọ, a o
si jà, gẹgẹ bi gbogbo eyiti OLUWA Ọlọrun
wa palaṣẹ fun wa. Ati olukuluku nyin dì
ihamọra ogun rẹ̀, ẹnyin mura lati gùn ori
òke na.
42 OLUWA si wi fun mi pe, Wi fun wọn
pe, Ẹ máṣe gòke lọ, bẽni ki ẹ máṣe jà; ni-
toriti emi kò sí lãrin nyin; ki a má ba lé
nyin niwaju awọn ọtá nyin.
43 Mo sọ fun nyin, ẹnyin kò si gbọ́;
ẹnyin ṣọ̀tẹ si aṣẹ OLUWA, ẹnyin sì kùgbu
lọ si ori òke na.
44 Awọn ọmọ Amori, ti ngbé ori òke na,
si jade tọ̀ nyin wá, nwọn si lepa nyin, bi
oyin ti iṣe, nwọn si run nyin ni Seiri, titi
dé Horma.
45 Ẹnyin si pada ẹ sí sọkun niwaju
OLUWA; ṣugbọn OLUWA kò gbọ́ ohùn
nyin, bẽni kò fetisi nyin.
46 Ẹnyin si joko ni Kadeṣi li ọjọ́ pupọ̀,
gẹgẹ bi ọjọ́ ti ẹnyin joko nibẹ̀.

## ORI 2.

NIGBANA li awa pada, awa si mú ọ̀na
wa pọ̀n lọ si aginjù li ọ̀na Okun Pupa,
bi OLUWA ti sọ fun mi: awa si yi òke
Seiri ká li ọjọ́ pupọ̀.
2 OLUWA si sọ fun mi pe,
3 Ẹnyin ti yi òke yi ká pẹ to: ẹ pada si
ìha ariwa.
4 Ki iwọ ki o si fi aṣẹ fun awọn enia, pe,
Ẹnyin o là ẹkùn awọn arakọnrin nyin kọja,
awọn ọmọ Esau ti ngbé Seiri; ẹru nyin
yio bà wọn: nitorina ẹ ṣọra nyin gidigidi:
5 Ẹ máṣe bá wọn jà; nitoripe emi ki
yio fun nyin ninu ilẹ wọn, ani to bi ẹsẹ̀
kan: nitoriti mo ti fi òke Seiri fun Esau
ni iní.
6 Owo ni ki ẹnyin fi rà onjẹ lọwọ wọn,
ti ẹnyin o jẹ; owo ni ki ẹnyin si fi rà omi
lọwọ wọn pẹlu, ti ẹnyin o mu.
7 Nitoriti OLUWA Ọlọrun rẹ ti bukún ọ
ninu iṣẹ ọwọ́ rẹ gbogbo: o ti mọ̀ ìrin rẹ li
aginjù nla yi: li ogoji ọdún yi OLUWA
Ọlọrun rẹ ti mbẹ pẹlu rẹ; ọdá ohun kan
kò dá ọ.
8 Nigbati awa si kọja lẹba awọn ara-
kọnrin wa awọn ọmọ Esau, ti ngbé Seiri,
li ọ̀na pẹtẹlẹ̀ lati Elati wá, ati lati Esion-
geberi wá, awa pada awa si kọja li ọ̀na
aginjù Moabu.
9 OLUWA si wi fun mi pe, Ẹ máṣe bi
awọn ara Moabu ninu, bẽni ki ẹ máṣe jà
wọn li ogun: nitoripe emi ki yio fi ninu
ilẹ rẹ̀ fun ọ ni iní; nitoriti mo ti fi Ari fun
awọn ọmọ Lotu ni iní.
10 (Awọn Emimu ti ngbé inu rẹ̀ ni ìgba
atijọ rí, awọn enia nla, nwọn si pọ̀, nwọn
si sigbọnlẹ, bi awọn ọmọ Anaki:
11 Ti a nkà kún awọn omirán, bi awọn
ọmọ Anaki; ṣugbọn awọn ara Moabu a ma
pè wọn ni Emimu.
12 Awọn ọmọ Hori pẹlu ti ngbé Seiri rí,
ṣugbọn awọn ọmọ Esau tẹle wọn, nwọn si
run wọn kuro niwaju wọn, nwọn si ngbé
ibẹ̀ ni ipò wọn; gẹgẹ bi Israeli ti ṣe si ilẹ-
iní rẹ̀, ti OLUWA fi fun wọn.)
13 Mo ní, Dide nisisiyi, ki ẹ si gòke odò
Seredi. Awa si gòke odò Seredi lọ.
14 Ìgba ti awa fi ti Kadeṣi-barnea wá,
titi awa fi gòke odò Seredi lọ, o jẹ́ ọgbọ̀n
ọdún o le mẹjọ; titi gbogbo iran awọn
ologun fi run kuro ninu ibudó, bi OLUWA
ti bura fun wọn.
15 Pẹlupẹlu ọwọ́ OLUWA lodi si wọn
nitõtọ, lati run wọn kuro ninu ibudó, titi
nwọn fi run tán.
16 Bẹ̃li o si ṣe, ti gbogbo awọn ologun
nì run, ti nwọn si kú tán ninu awọn enia
na,
17 OLUWA si sọ fun mi pe,
18 Iwọ o là ilẹ Ari lọ li oni, li àgbegbe
Moabu:
19 Nigbati iwọ ba sunmọtosi awọn ọmọ
Ammoni, máṣe bi wọn ninu, bẽni ki o
máṣe bá wọn jà: nitoripe emi ki yio fi
ninu ilẹ awọn ọmọ Ammoni fun ọ ni iní:
nitoriti mo ti fi i fun awọn ọmọ Lotu ni
iní.
20 (A si kà eyinì pẹlu si ilẹ awọn omi-
rán; awọn omirán ti ngbé inu rẹ̀ rí; awọn

Digitized by Google

ọmọ Ammoni a si ma pè wọn ni Samsum-
mimu.
21 Awọn enia nla, ti nwọn si pọ̀ nwọn
si sigbọnlẹ, bi awọn ọmọ Anaki; ṣugbọn
OLUWA run wọn niwaju wọn; nwọn si
tẹle wọn, nwọn si ngbé ibẹ̀ ni ipò wọn;
22 Bi o ti ṣe fun awọn ọmọ Esau, ti
ngbé Seiri, nigbati o run awọn ọmọ Hori
kuro niwaju wọn; ti nwọn si tẹle wọn, ti
nwọn si ngbé ibẹ̀ ni ipò wọn titi di oni-
oloni:
23 Ati awọn ọmọ Affimu ti ngbé awọn
ileto, titi dé Gasa, awọn ọmọ Kaftori, ti o
ti ọdọ Kaftori wá, run wọn, nwọn si ngbé
ibẹ̀ ni ipò wọn.)
24 Ẹ dide, ẹ mú ọ̀na nyin pọ̀n, ki ẹ si
gòke odò Arnoni: wò o, emi fi Sihoni ọmọ
Amori, ọba Heṣboni lé ọ lọwọ, ati ilẹ rẹ̀:
bẹ̀rẹsi gbà a, ki o si bá a jagun.
25 Li oni yi li emi o bẹ̀rẹsi fi ìfoya rẹ,
ati ẹ̀ru rẹ sara awọn orilẹ-ède ti mbẹ ni
gbogbo abẹ ọrun, ti yio gburó rẹ, ti yio si
warìri, ti yio si ṣe ipàiya nitori rẹ.
26 Mo si rán onṣẹ lati aginjù Kedemotu
lọ sọdọ Sihoni ọba Heṣboni pẹlu ọ̀rọ alafia,
wipe,
27 Jẹ ki emi ki o là ilẹ rẹ kọja lọ: ọ̀na
opópo li emi o gbà, emi ki yio yà si ọtún
tabi si òsi.
28 Li owo ni ki iwọ ki o tà onjẹ fun mi,
ki emi ki o jẹ; li owo ni ki iwọ ki o si fun
mi li omi, ki emi ki o mu: kìki ki nsá fi
ẹsẹ̀ mi kọja;
29 Bi awọn ọmọ Esau ti ngbé Seiri, ati
awọn ara Moabu ti ngbé Ari, ti ṣe si mi;
titi emi o fi gòke Jordani si ilẹ ti OLUWA
Ọlọrun wa fi fun wa.
30 Ṣugbọn Sihoni ọba Heṣboni kò jẹ ki
a kọja lẹba on: nitoriti OLUWA Ọlọrun rẹ
mu u li àiya le, o sọ ọkàn rẹ̀ di agídi, ki o
le fi on lé ọ lọwọ, bi o ti ri li oni yi.
31 OLUWA si sọ fun mi pe, Wò o, emi ti
bẹ̀rẹsi fi Sihoni ati ilẹ rẹ̀ fun ọ niwaju rẹ:
bẹ̀rẹsi gbà a, ki iwọ ki o le ní ilẹ rẹ̀.
32 Nigbana ni Sihoni jade si wa, on ati
gbogbo awọn enia rẹ̀, fun ìja ni Jahasi.
33 OLUWA Ọlọrun si fi i lé wa lọwọ ni-
waju wa; awa si kọlù u, ati awọn ọmọ rẹ̀,
ati gbogbo awọn enia rẹ̀.
34 Awa si kó gbogbo ilu rẹ̀ ni ìgba na,
awa si run awọn ọkọnrin patapata, ati
awọn obirin, ati awọn ọmọ wẹ́wẹ, ni gbo-
gbo ilu; awa kò jẹ ki ọkan ki o kù:
35 Kìki ohunọ̀sin li a kó ni ikogun fun
ara wa, ati ikogun ilu wọnni ti awa kó.
36 Lati Aroeri lọ, ti mbẹ leti afonifoji
Arnoni, ati lati ilu nì lọ ti mbẹ lẹba afoni-
foji nì, ani dé Gileadi, kò sí ilu kan ti o le
jù fun wa: OLUWA Ọlọrun wa fi gbogbo
wọn fun wa:
37 Kìki ilẹ awọn ọmọ Ammoni ni iwọ
kò sunmọ, tabi ibikibi lẹba odò Jaboku,
tabi ilu òke wọnni, tabi ibikibi ti OLUWA
Ọlọrun wa kọ̀ fun wa.

## ORI 3.

NIGBANA li awa pada, a si lọ soke li
ọ̀na Baṣani: Ogu ọba Baṣani si jade
si wa, on ati gbogbo awọn enia rẹ̀, fun ìja
ni Edrei.
2 OLUWA si wi fun mi pe, Máṣe bẹ̀ru
rẹ̀; nitoripe emi ti fi on, ati gbogbo awọn
enia rẹ̀, ati ilẹ rẹ̀, lé ọ lọwọ; iwọ o si ṣe si
i bi iwọ ti ṣe si Sihoni ọba ọmọ Amori,
ti ngbé Heṣboni.
3 Bẹ̃ni OLUWA Ọlọrun wa fi Ogu, ọba
Baṣani, ati gbogbo awọn enia rẹ̀, lé wa
lọwọ pẹlu: awa si kọlù u titi kò si kù
ẹnikan silẹ fun u.
4 Awa si kó gbogbo ilu rẹ̀ ni ìgba na;
kò sí ilu kan ti awa kò gbà lọwọ wọn;
ọgọta ilu, gbogbo ẹkùn Argobu, ilẹ ọba
Ogu ni Baṣani.
5 Gbogbo ilu wọnyi li a mọ odi giga si
pẹlu ibode, ati idabu-ẹ̀kun; laikà ilu alai-
lodi ọ̀pọlọpọ.
6 Awa si run wọn patapata, bi awa ti ṣe
si Sihoni ọba Heṣboni, ni rirun awọn ọkọn-
rin, obirin, ati awọn ọmọ wẹ́wẹ patapata,
ni ilu na gbogbo.
7 Ṣugbọn gbogbo ohunọ̀sin, ati ikogun
ilu wọnni li awa kó ni ikogun fun ara
wa.
8 Nigbana li awa gbà li ọwọ́ awọn ọba
ọmọ Amori mejeji, ilẹ ti mbẹ ni ìha ihin
Jordani, lati afonifoji Arnoni lọ dé òke
Hermoni;
9 (Awọn ara Sidoni a ma pè Hermoni ni
Sirioni, ati awọn ọmọ Amori a si ma pè e
ni Seniri;)
10 Gbogbo ilu pẹtẹlẹ̀ na, ati gbogbo Gi-
leadi, ati gbogbo Baṣani, dé Saleka ati
Edrei, awọn ilu ilẹ ọba Ogu ni Baṣani.
11 (Ogu ọba Baṣani nikanṣoṣo li o sá kù
ninu awọn omirán iyokù; kiyesi i, akete
rẹ̀ jẹ́ akete irin; kò ha wà ni Rabba ti
awọn ọmọ Ammoni? igbọnwọ mẹsan ni
gigùn rẹ̀, igbọnwọ mẹrin si ni ibú rẹ̀, ni
igbọnwọ ọkọnrin.)
12 Ati ilẹ na yi, ti awa gbà ni ìgbana,
lati Aroeri, ti mbẹ lẹba afonifoji Arnoni,

Digitized by Google

ati àbọ òke Gileadi, ati ilu inu rẹ̀, ni mo
fi fun awọn ọmọ Reubeni, ati fun awọn
ọmọ Gadi:
13 Ati iyokù Gileadi, ati gbogbo Baṣani,
ilẹ ọba Ogu, ni mo fi fun àbọ ẹ̀ya Manasse;
gbogbo ẹkùn Argobu, pẹlu gbogbo Baṣani.
(Ti a ma pè ni ilẹ awọn omirán.
14 Jairi ọmọ Manasse mú gbogbo ilẹ
Argobu, dé opinlẹ́ Geṣuri ati Maakati; o
si sọ wọn, ani Baṣan, li orukọ ara rẹ̀, ni
Haffotu-jairi titi di oni.)
15 Mo si fi Gileadi fun Makiri.
16 Ati awọn ọmọ Reubeni, ati awọn
ọmọ Gadi ni mo fi fun lati Gileadi, ani dé
afonifoji Arnoni, agbedemeji afonifoji, ati
opinlẹ rẹ̀; ani dé odò Jaboku, ti iṣe ipinlẹ
awọn ọmọ Ammoni;
17 Pẹtẹlẹ̀ nì pẹlu, ati Jordani ati opinlẹ
rẹ̀, lati Kinnereti lọ titi dé okun pẹtẹlẹ̀,
ani Okun Iyọ̀, nisalẹ awọn orisun Pisga ni
ìha ìla-õrùn.
18 Mo si fun nyin li aṣẹ ni ìgbana, wipe,
OLUWA Ọlọrun nyin ti fi ilẹ yi fun nyin
lati ní i: ẹnyin o si kọja si ìha keji ni
ihamọra ogun niwaju awọn arakọnrin nyin,
awọn ọmọ Israeli, gbogbo awọn akọni
ọkọnrin.
19 Kìki awọn aya nyin, ati awọn ọmọ
wẹ́wẹ nyin, at ohunọ̀sin nyin, (emi mọ̀ pe
ẹnyin lí ohunọ̀sin pupọ̀,) ni yio duro ni ilu
nyin ti mo ti fi fun nyin;
20 Titi OLUWA o fi fi isimi fun awọn
arakọnrin nyin, gẹgẹ bi o ti fi fun ẹnyin,
ati titi awọn pẹlu yio fi ní ilẹ na ti OLUWA
Ọlọrun nyin ti fi fun wọn loke Jordani:
nigbana li ẹnyin o pada olukuluku si ilẹ-iní
rẹ̀, ti mo ti fi fun nyin.
21 Emi si fi aṣẹ fun Joṣua ni ìgbana,
wipe, Oju rẹ ti ri gbogbo eyiti OLUWA
Ọlọrun nyin ti ṣe si awọn ọba mejeji wọnyi:
bẹ̃ni OLUWA yio ṣe si gbogbo ilẹ-ọba nibiti
iwọ o kọja.
22 Ẹnyin kò gbọdọ bẹ̀ru wọn: nito-
ripe OLUWA Ọlọrun nyin, on ni yio jà
fun nyin.
23 Emi si bẹ̀ OLUWA ni ìgba na, wipe,
24 Oluwa ỌLỌRUN, iwọ ti bẹ̀rẹsi fi
titobi rẹ hàn fun iranṣẹ rẹ, ati ọwọ́ agbara
rẹ: nitoripe Ọlọrun wo ni li ọrun ati li
aiye, ti o le ṣe gẹgẹ bi iṣẹ rẹ, ati gẹgẹ bi
iṣẹ-agbara rẹ?
25 Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki emi ki o kọja si ìha
keji, ki emi si ri ilẹ rere na ti mbẹ loke
Jordani, òke daradara nì, ati Lebanoni.
26 Ṣugbọn OLUWA binu si mi nitori
nyin, kò si gbọ́ ti emi: OLUWA si wi fun
mi pe, O to gẹ; má tun bá mi sọ ọ̀rọ
yi mọ́.
27 Gùn ori òke Pisga lọ, ki o si gbé oju
rẹ soke si ìha ìwọ-õrùn, ati si ìha ariwa,
ati si ìha gusù, ati si ìha ìla-õrùn, ki o si fi
oju rẹ wò o: nitoripe iwọ ki yio gòke
Jordani yi.
28 Ṣugbọn fi aṣẹ fun Joṣua, ki o si gbà a
niyanju, ki o si mu u li ọkàn le: nitoripe
on ni yio gòke lọ niwaju awọn enia yi, on
o si mu wọn ni ilẹ na ti iwọ o ri.
29 Awa si joko li afonifoji ti o kọjusi
Beti-peori.

ORI 4.

NJẸ nisisiyi Israeli, fetisi ìlana ati idajọ,
ti emi nkọ́ nyin, lati ṣe wọn; ki
ẹnyin ki o le yè, ki ẹ si lọ igba ilẹ na ti
OLUWA, Ọlọrun awọn baba nyin fi fun
nyin.
2 Ẹ kò gbọdọ bukún ọ̀rọ na ti mo palaṣẹ
fun nyin, bẹ̃li ẹnyin kò gbọdọ bù kuro ninu
rẹ̀, ki ẹnyin ki o le pa ofin OLUWA Ọlọrun
nyin mọ́, ti mo palaṣẹ fun nyin.
3 Oju nyin ti ri ohun ti OLUWA ṣe nito-
ri Baali-peori: nitoripe gbogbo awọn ọkọn-
rin ti o tẹle Baali-peori lẹhin, OLUWA
Ọlọrun rẹ ti run wọn kuro lãrin rẹ.
4 Ṣugbọn ẹnyin ti o faramọ́ OLUWA
Ọlọrun nyin, gbogbo nyin mbẹ lãye li oni.
5 Wò o, emi ti kọ́ nyin ni ìlana ati ida-
jọ, bi OLUWA Ọlọrun mi ti paṣẹ fun mi, pe
ki ẹnyin ki o le ma ṣe bẹ̃ ni ilẹ na nibiti
ẹnyin nlọ lati gbà a.
6 Nitorina ẹ pa wọn mọ́, ki ẹ si ma ṣe
wọn; nitoripe eyi li ọgbọ́n nyin ati oye
nyin li oju awọn orilẹ-ède, ti yio gbọ́ gbo-
gbo ìlana wọnyi, ti yio si wipe, Ọlọgbọ́n ati
amoye enia nitõtọ ni orilẹ-ède nla yi.
7 Nitori orilẹ-ède nla wo li o wà, ti o ní
Ọlọrun sunmọ wọn to, bi OLUWA Ọlọrun
wa ti ri ninu ohun gbogbo ti awa kepè
e si?
8 Ati orilẹ-ède nla wo li o si wà, ti o ní
ìlana ati idajọ ti iṣe ododo to bi gbogbo ofin
yi, ti mo fi siwaju nyin li oni?
9 Kìki ki iwọ ki o ma kiyesara rẹ, ki o
si ṣọ́ ọkàn rẹ gidigidi, ki iwọ ki o má ba
gbagbé ohun ti oju rẹ ti ri, ati ki nwọn ki
o má ba lọ kuro li àiya rẹ li ọjọ́ aiye rẹ gbo-
gbo; ṣugbọn ki iwọ ki o ma fi wọn kọ́ awọn
ọmọ rẹ, ati awọn ọmọ ọmọ rẹ;
10 Li ọjọ́ ti iwọ duro niwaju OLUWA
Ọlọrun rẹ ni Horebu, nigbati OLUWA wi
fun mi pe, Pe awọn enia yi jọ fun mi, emi
o si mu wọn gbọ́ ọ̀rọ mi, ki nwọn ki o le

Digitized by Google

ma kọ́ ati bẹ̀ru mi li ọjọ́ gbogbo ti nwọn o wà lori ilẹ, atí ki nwọn ki o le ma kọ́ awọn ọmọ wọn.

11 Ẹnyin si sunmọtosi, ẹ si duro nisalẹ òke nì; òke na si njóna dé agbedemeji ọrun, pẹlu òkunkun, ati awọsanma, ati òkunkun biribiri.

12 OLUWA si sọ̀rọ si nyin lati ãrin iná na wá: ẹnyin gbọ́ ohùn ọ̀rọ na, ṣugbọn ẹ kò ri apẹrẹ kan; kìki ohùn li ẹnyin gbọ́.

13 O si sọ majẹmu rẹ̀ fun nyin, ti o palaṣẹ fun nyin lati ṣe, ani ofin mẹwa nì; o si kọ wọn sara walã okuta meji.

14 OLUWA si paṣẹ fun mi ni ìgba na lati kọ́ nyin ni ìlana ati idajọ, ki ẹnyin ki o le mã ṣe wọn ni ilẹ na nibiti ẹnyin nlọ lati gbà a.

15 Nitorina ki ẹnyin ki o ma kiyesara nyin gidigidi, nitoripe ẹnyin kò ri apẹrẹ kan li ọjọ́ ti OLUWA bá nyin sọ̀rọ ni Horebu lati ãrin iná wá:

16 Ki ẹnyin ki o má ba bà ara nyin jẹ́, ki ẹ má si lọ ṣe ere gbigbẹ, apẹrẹ ohunkohun, aworán akọ tabi abo.

17 Aworán ẹrankẹran ti mbẹ lori ilẹ, awọrán ẹiyẹkẹiyẹ ti nfò li oju-ọrun.

18 Aworán ohunkohun ti nrakò lori ilẹ, aworán ẹjakẹja ti mbẹ ninu omi nisalẹ ilẹ:

19 Ati ki iwọ ki o má ba gbé oju rẹ soke ọrun, nigbati iwọ ba si ri õrùn, ati oṣupa, ati irawọ, ani gbogbo ogun ọrun, ki a má ba sún ọ lọ ibọ wọn, ki o si ma sìn wọn, eyiti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun gbogbo orilẹ-ède labẹ ọrun gbogbo.

20 Ṣugbọn OLUWA ti gbà nyin, o si mú nyin lati ileru irin, lati Egipti jade wá, lati ma jẹ́ enia iní fun u, bi ẹnyin ti ri li oni yi.

21 OLUWA si binu si mi nitori nyin, o si bura pe, emi ki yio gòke Jordani, ati pe emi ki yio wọ̀ inu ilẹ rere nì, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ni ilẹ-iní.

22 Ṣugbọn emi o kú ni ilẹ yi, emi ki yio gòke odò Jordani: ṣugbọn ẹnyin o gòke ẹnyin o si gbà ilẹ rere na.

23 Ẹ ma ṣọra nyin, ki ẹnyin má ba gbagbé majẹmu OLUWA Ọlọrun nyin, ti o ti bá nyin dá, ki ẹnyin má ba lọ ṣe ere finfin fun ara nyin, tabi aworán ohunkohun ti OLUWA Ọlọrun rẹ ti kọ̀ fun ọ.

24 Nitori OLUWA Ọlọrun rẹ ajonirun iná ni, Ọlọrun owú.

25 Nigbati iwọ ba bi ọmọ, ati ọmọ ọmọ, ti ẹ ba si pẹ ni ilẹ na, ti ẹ si bà ara nyin jẹ́, ti ẹ si ṣe ere finfin, tabi aworán ohunkohun, ti ẹ si ṣe eyiti o buru li oju OLUWA Ọlọrun rẹ lati mu u binu:

26 Mo pè orun ati aiye jẹri si nyin li oni, pe lọ́gan li ẹnyin o run kuro patapata ni ilẹ na nibiti ẹnyin ngòke Jordani lọ lati gbà a; ẹnyin ki yio lò ọjọ́ nyin pẹ ninu rẹ̀, ṣugbọn ẹnyin o si run patapata.

27 OLUWA yio si tú nyin ká ninu awọn orilẹ-ède, diẹ ni ẹnyin o si kù ni iye ninu awọn orilẹ-ède, nibiti OLUWA yio darí nyin si.

28 Nibẹ̀ li ẹnyin o si ma sìn oriṣa, iṣẹ ọwọ́ enia, igi ati okuta, ti kò riran, ti kò si gbọran, ti kò jẹun, ti kò si gbõrun.

29 Ṣugbọn bi iwọ ba wá OLUWA Ọlọrun rẹ lati ibẹ̀ lọ, iwọ o ri i, bi iwọ ba fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ wá a.

30 Nigbati iwọ ba mbẹ ninu ipọnju, ti nkan gbogbo wọnyi ba si bá ọ, nikẹhin ọjọ́, bi iwọ ba yipada si OLUWA Ọlọrun rẹ, ti iwọ ba si gbà ohùn rè gbọ́:

31 Nitoripe Ọlọrun alãnu ni OLUWA Ọlọrun rẹ; on ki yio kọ̀ ọ silẹ bẽni ki yio run ọ, bẽni ki yio gbagbé majẹmu awọn baba rẹ, ti o ti bura fun wọn.

32 Njẹ bère nisisiyi niti ọjọ́ igbãni, ti o ti mbẹ ṣaju rẹ, lati ọjọ́ ti Ọlọrun ti dá enia sori ilẹ, ki o si bère lati ìha ọrun kini dé ìha keji, bi irú nkan bi ohun nla yi wà rí, tabi bi a gburó irú rẹ̀ rí?

33 Awọn enia kan ha gbọ́ ohùn Ọlọrun rí ki o ma bá wọn sọ̀rọ lati ãrin iná wá, bi iwọ ti gbọ́, ti o si wà lãye?

34 Tabi Ọlọrun ha dán a wò rí lati lọ mú orilẹ-ède kan fun ara rẹ̀ lati ãrin orilẹ-ède miran wá, nipa idanwò, nipa àmi, ati nipa iṣẹ-iyanu, ati nipa ogun, ati nipa ọwọ́ agbara, ati nipa ninà apa, ati nipa ẹ̀ru nla, gẹgẹ bi gbogbo eyiti OLUWA Ọlọrun nyin ṣe fun nyin ni Egipti li oju nyin?

35 Iwọ li a fihàn, ki iwọ ki o le mọ̀ pe OLUWA on li Ọlọrun; kò sí ẹlomiran lẹhin rẹ̀.

36 O mu ọ gbọ́ ohùn rẹ̀ lati ọrun wá, ki o le kọ́ ọ: ati lori ilẹ aiye o fi iná nla rẹ̀ hàn ọ; iwọ si gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀ lati ãrin iná wá.

37 Ati nitoriti o fẹ́ awọn baba rẹ, nitorina li o ṣe yàn irú-ọmọ wọn lẹhin wọn, o si fi agbara nla rẹ̀ mú ọ lati Egipti jade wá li oju rẹ̀;

38 Lati lé awọn orilẹ-ède jade kuro niwaju rẹ, ti o tobi, ti o si lagbara jù ọ lọ, lati mú ọ wọle, lati fi ilẹ wọn fun ọ ni iní, bi o ti ri li oni yi.

39 Nitorina ki iwọ ki o mọ̀ li oni, ki o si rò li ọkàn rẹ pe, OLUWA on li Ọlọrun

Digitized by Google

loke ọrun, ati lori ilẹ nisalẹ: kò sí ẹlomiran.

40 Nitorina ki iwọ ki o pa ìlana rẹ̀ mọ́, ati ofin rẹ̀, ti mo palaṣẹ fun ẹ li oni, ki o le dara fun ọ, ati fun awọn ọmọ rẹ lẹhin rẹ, ati ki iwọ ki o le mu ọjọ́ rẹ pẹ lori ilẹ, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ lailai.

41 Nigbana ni Mose yà ilu mẹta sọ̀tọ ni ìha ihin Jordani si ìha ìla-õrùn.

42 Ki apania ki e le ma sá sibẹ̀, ti o ba ṣì ẹnikeji rẹ̀ pa, ti kò si korira rẹ̀ ni ìgba atijọ rí; ati pe bi o ba sá si ọkan ninu ilu wọnyi ki o le là:

43 Beseri ni ijù, ni ilẹ pẹtẹlẹ̀, ti awọn ọmọ Reubeni; ati Ramotu ni Gileadi, ti awọn ọmọ Gadi; ati Golani ni Baṣani, ti awọn ọmọ Manasse.

44 Eyi li ofin na ti Mose filelẹ niwaju awọn ọmọ Israeli:

45 Wọnyi li ẹrí, ati ìlana, ati idajọ, ti Mose filelẹ fun awọn ọmọ Israeli, lẹhin igbati nwọn ti Egipti jade wá;

46 Ni ìha ihin Jordani, ni afonifoji ti o kọjusi Beti-peori, ni ilẹ Sihoni ọba awọn ọmọ Amori, ti ngbé Heṣboni, ẹniti Mose ati awọn ọmọ Israeli kọlù, lẹhin igbati nwọn ti Egipti jade wá:

47 Nwọn si gbà ilẹ rẹ̀, ati ilẹ Ogu ọba Baṣani, awọn ọba Amori mejeji ti mbẹ ni ìha ihin Jordani si ìha ìla-õrùn;

48 Lati Aroeri lọ, ti mbẹ leti afonifoji Arnoni, ani dé òke Sioni (ti iṣe Hermoni,)

49 Ati gbogbo pẹtẹlẹ̀ nì, ni ìha ihin Jordani ni ìha ìla-õrùn, ani dé okun pẹtẹlẹ̀ nì, nisalẹ awọn orisun Pisga.

## ORI 5.

MOSE si pè gbogbo Israeli, o si wi fun wọn pe, Israeli, gbọ́ ìlana ati idajọ ti emi nsọ li etí nyin li oni, ki ẹnyin ki o le kọ́ wọn, ki ẹ si ma pa wọn mọ́, lati ma ṣe wọn.

2 OLUWA Ọlọrun wa bá wa dá majẹmu ni Horebu.

3 OLUWA kò bá awọn baba wa dá majẹmu yi, bikoṣe awa, ani awa, ti gbogbo wa mbẹ lãye nihin li oni.

4 OLUWA bá nyin sọ̀rọ li ojukoju lori òke na, lati ãrin iná wá,

5 (Emi duro li agbedemeji OLUWA ati ẹnyin ni ìgba na, lati sọ ọ̀rọ OLUWA fun nyin: nitoripe ẹnyin bẹ̀ru nitori iná na, ẹnyin kò si gòke lọ sori òke na;) wipe,

6 Emi li OLUWA Ọlọrun rẹ, ti o mú ọ lati ilẹ Egipti, lati oko-ẹrú jade wá.

7 Iwọ kò gbọdọ ní ọlọrun miran pẹlu mi.

8 Iwọ kò gbọdọ yá ere fun ara rẹ, tabi aworán apẹrẹ kan ti mbẹ loke ọrun, tabi ti mbẹ ni ilẹ nisalẹ, tabi ti mbẹ ninu omi ni isalẹ ilẹ:

9 Iwọ kò gbọdọ tẹ̀ ori rẹ ba fun wọn, bẽni iwọ kò gbọdọ sìn wọn: nitoripe emi OLUWA Ọlọrun rẹ Ọlọrun owú ni mi, ti mbẹ̀ ẹ̀ṣẹ awọn baba wò lara awọn ọmọ, ati lara iran kẹta ati ẹkẹrin ninu awọn ti o korira mi.

10 Emi a si ma ṣe ãnu fun ẹgbẹgbẹrun awọn ti o fẹ́ mi, ti nwọn si pa ofin mi mọ́.

11 Iwọ kò gbọdọ pè orukọ OLUWA Ọlọrun rẹ li asan: nitoriti OLUWA ki yio mu ẹniti o pè orukọ rẹ̀ li asan bi alailẹṣẹ lọrùn.

12 Kiyesi ọjọ́-isimi lati yà a simimọ́, bi OLUWA Ọlọrun rẹ ti paṣẹ fun ọ.

13 Ijọ́ mẹfa ni iwọ o ṣiṣẹ, ti iwọ o si ṣe iṣẹ rẹ gbogbo.

14 Ṣugbọn ọjọ́ keje li ọjọ́-isimi OLUWA Ọlọrun rẹ: ninu rẹ̀ iwọ kò gbọdọ ṣe iṣẹkiṣẹ kan, iwọ, ati ọmọ rẹ ọkọnrin, ati ọmọ rẹ obirin, ati ọmọ-ọdọ rẹ ọkọnrin, ati ọmọ-ọdọ rẹ obirin, ati akọmalu rẹ, ati kẹtẹkẹtẹ rẹ, ati ohunọ̀sin rẹ kan, ati ajejò ti mbẹ ninu ibode rẹ; ki ọmọ-ọdọ rẹ ọkọnrin ati ọmọ ọdọ rẹ obirin ki o le simi gẹgẹ bi iwọ.

15 Si ranti pe iwọ ti ṣe iranṣẹ ni ilẹ Egipti, ati pe OLUWA Ọlọrun rẹ mú ọ lati ibẹ̀ jade wá nipa ọwọ́ agbara, ati nipa ninà apa: nitorina li OLUWA Ọlọrun rẹ ṣe paṣẹ fun ọ lati pa ọjọ́-isimi mọ́.

16 Bọ̀wọ fun baba ati iya rẹ, bi OLUWA Ọlọrun rẹ ti paṣẹ fun ọ: ki ọjọ́ rẹ ki o le pẹ, ati ki o le dara fun ọ, ni ilẹ ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ.

17 Iwọ kò gbọdọ pania.

18 Bẽni iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga.

19 Bẽni iwọ kò gbọdọ jale.

20 Bẽni iwọ kò gbọdọ jẹri-eké si ẹnikeji rẹ.

21 Bẽni iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro si aya ẹnikeji rẹ; bẽni iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro si ile ẹnikeji rẹ, oko rẹ̀, ati ọmọ-ọdọ rẹ̀ ọkọnrin, ati ọmọ-ọdọ rẹ̀ obirin, akọmalu rẹ̀, ati kẹtẹkẹtẹ rẹ̀, ati ohun gbogbo ti iṣe ti ẹnikeji rẹ.

22 Ọrọ wọnyi ni OLUWA sọ fun gbogbo ijọ nyin lori òke lati ãrin iná, awọsanma, ati lati inu òkunkun biribiri wá, pẹlu ohùn nla: kò si fi kún u mọ́. O si kọ wọn sara walã okuta meji, o si fi wọn fun mi.

23 O si ṣe, nigbati ẹnyin gbọ́ ohùn nì lati ãrin òkunkun na wá, ti òke na si njó,

Digitized by Google

ti ẹnyin sunmọ ọdọ mi, gbogbo olori awọn
ẹ̀ya nyin, ati awọn àgba nyin :
24 Ẹnyin si wipe, Kiyesi i, OLUWA Ọlọ-
run wa fi ogo rẹ̀ ati titobi rẹ̀ hàn wa, awa
si ti gbọ́ ohùn rẹ̀ lati ãrin iná wá : awa ti
ri li oni pe, OLUWA a ma ba enia sọ̀rọ̀, on
a si wà lãye.
25 Njẹ nisisiyi ẽṣe ti awa o fi kú ? nito-
ripe iná nla yi yio jó wa run : bi awa ba
tun gbọ́ ohùn OLUWA Ọlọrun wa, njẹ awa
o kú.
26 Nitoripe tani mbẹ ninu gbogbo araiye
ti o ti igbọ́ ohùn Ọlọrun alãye ti nsọ̀rọ lati
ãrin iná wá, bi awa ti gbọ́, ti o si wà lãye ?
27 Iwọ sunmọtosi, ki o si gbọ́ gbogbo
eyiti OLUWA Ọlọrun wa yio wi : ki iwọ ki
o sọ fun wa gbogbo ohun ti OLUWA Ọlọrun
wa yio sọ fun ọ : awa o si gbọ́, awa o si ṣe e.
28 OLUWA si gbọ́ ohùn ọ̀rọ nyin, nigbati
ẹnyin sọ fun mi ; OLUWA si sọ fun mi pe,
emi ti gbọ́ ohùn ọ̀rọ awọn enia yi, ti nwọn
sọ fun ọ : nwọn wi rere ni gbogbo eyiti
nwọn sọ.
29 Irú ọkàn bayi iba ma wà ninu wọn,
ki nwọn ki o le ma bẹ̀ru mi, ki nwọn ki o
si le ma pa gbogbo ofin mi mọ́ nigbagbo-
gbo, ki o le dara fun wọn, ati fun awọn
ọmọ wọn titilai !
30 Lọ wi fun wọn pe, Ẹ pada lọ sinu agọ́
nyin.
31 Ṣugbọn, iwọ, duro nihin lọdọ mi,
emi o si sọ ofin nì gbogbo fun ọ, ati ilana,
ati idajọ, ti iwọ o ma kọ́ wọn, ki nwọn ki
o le ma ṣe wọn ni ilẹ na ti mo ti fi fun wọn
lati ní.
32 Nitorina ki ẹnyin ki o ma kiyesi ati
ṣe bi OLUWA Ọlọrun nyin ti paṣẹ fun nyin :
ki ẹnyin ki o máṣe yi si ọtún tabi si òsi.
33 Ki ẹnyin ki o si ma rìn ninu gbogbo
ọ̀na ti OLUWA Ọlọrun nyin palaṣẹ fun nyin,
ki ẹnyin ki o le yè, ki o si le dara fun nyin,
ati ki ẹnyin ki o le mu ọjọ́ nyin pẹ ni ilẹ
ti ẹnyin yio ní.

## ORI 6.

NJẸ wọnyi li ofin, ìlana, ati idajọ, ti
OLUWA Ọlọrun nyin ti palaṣẹ lati ma
kọ́ nyin, ki ẹnyin ki o le ma ṣe wọn ni ilẹ
nibiti ẹnyin gbé nlọ lati gbà a :
2 Ki iwọ ki o le ma bẹ̀ru OLUWA Ọlọrun
rẹ, lati pa gbogbo ìlana rẹ̀ ati ofin rẹ̀ mọ́,
ti emi fi fun ọ, iwọ, ati ọmọ rẹ, ati ọmọ
ọmọ rẹ, li ọjọ́ aiye rẹ gbogbo ; ki ọjọ́ rẹ ki
o le pẹ.
3 Nitorina gbọ́, Israeli, ki o si ma ki-
yesi i lati ṣe e ; ki o le dara fun ọ, ati ki
ẹnyin ki o le ma pọ̀si i li ọ̀pọlọpọ, bi
OLUWA Ọlọrun awọn baba rẹ ti ṣe ileri fun
ọ, ni ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin.
4 Gbọ́, Israeli : OLUWA Ọlọrun wa,
OLUWA kan ni.
5 Ki iwọ ki o si fi gbogbo àiya rẹ, ati
gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo agbara rẹ fẹ́
OLUWA Ọlọrun rẹ.
6 Ati ọ̀rọ wọnyi, ti mo palaṣẹ fun ọ li
oni, ki o ma wà li àiya rẹ :
7 Ki iwọ ki o si ma fi wọn kọ́ awọn ọmọ
rẹ gidigidi, ki iwọ ki o si ma fi wọn ṣe ọ̀rọ
isọ nigbati iwọ ba joko ninu ile rẹ, ati
nigbati iwọ ba nrìn li ọ̀na, ati nigbati iwọ
ba dubulẹ, ati nigbati iwọ ba dide.
8 Ki iwọ ki o si so wọn mọ́ ọwọ́ rẹ fun
àmi, ki nwọn ki o si ma ṣe ọja-igbaju ni-
waju rẹ.
9 Ki iwọ ki o si kọ wọn sara opó ile rẹ,
ati sara ilẹkun ọ̀na-ode rẹ.
10 Yio si ṣe, nigbati OLUWA Ọlọrun rẹ
ba mú ọ dé ilẹ na, ti o bura fun awọn baba
rẹ fun Abrahamu, fun Isaaki, ati fun Ja-
kobu, lati fun ọ ni ilu ti o tobi ti o si dara,
ti iwọ kò mọ̀,
11 Ati ile ti o kún fun ohun rere gbogbo,
ti iwọ kò kún, ati kanga wiwà, ti iwọ kò
wà, ọgbà-àjara ati igi oróro, ti iwọ kò
gbìn ; nigbati iwọ ba jẹ tán ti o ba si yó ;
12 Kiyesara rẹ ki iwọ ki o má ba gba-
gbé OLUWA ti o mú ọ lati ilẹ Egipti jade
wá, kuro li oko-ẹrú.
13 Bẹ̀ru OLUWA Ọlọrun rẹ, ki o si ma
sìn i, ki o si ma bura li orukọ rẹ̀.
14 Ẹnyin kò gbọdọ tọ̀ ọlọrun miran lẹ-
hin, ninu oriṣa awọn enia, ti o yi nyin ká
kiri ;
15 Nitori OLUWA Ọlọrun rẹ Ọlọrun owú
ni ninu nyin ; ki ibinu OLUWA Ọlọrun rẹ
ki o má ba rú si ọ, on a si run ọ kuro lori
ilẹ.
16 Ẹnyin kò gbọdọ dán OLUWA Ọlọrun
nyin wò, bi ẹnyin ti dan a wò ni Massa.
17 Ki ẹnyin ki o pa ofin OLUWA Ọlọrun
nyin mọ́ gidigidi, ati ẹrí rẹ̀, ati ìlana rẹ̀, ti
o filelẹ li aṣẹ fun ọ.
18 Ki iwọ ki o ma ṣe eyiti o tọ́, ti o si
dara li oju OLUWA : ki o le dara fun ọ, ati
ki iwọ ki o le wọ̀ ilẹ rere nì lọ ki o si gbà a,
eyiti OLUWA bura fun awọn baba rẹ,
19 Lati tì awọn ọtá rẹ gbogbo jade kuro
niwaju rẹ, bi OLUWA ti wi.
20 Nigbati ọmọ rẹ ba bi ọ lère lẹhin-ọla,
Wipe, Ẽredi ẹrí, ati ìlana, ati idajọ wọnyi,
ti OLUWA Ọlọrun filelẹ li aṣẹ fun nyin ?
21 Nigbana ni ki iwọ ki o wi fun ọmọ

Digitized by Google

rẹ pe, Ẹrú Farao li awa ti ṣe ni Egipti;
Oluwa si fi ọwọ́ agbara mú wa jade lati
Egipti wá.
22 Oluwa si fi àmi ati iṣẹ-iyanu, ti o
tobi ti o si buru hàn lara Egipti, lara Farao,
ati lara gbogbo ara ile rẹ̀ li oju wa:
23 O si mú wa jade lati ibẹ̀ wá, ki o le
mú wa wọ̀ inu rẹ̀, lati fun wa ni ilẹ na ti o
bura fun awọn baba wa.
24 Oluwa si pa a laṣẹ fun wa, lati ma
ṣe gbogbo ìlana wọnyi, lati ma bẹ̀ru Oluwa
Ọlọrun wa, fun ire wa nigbagbogbo, ki o
le pa wa mọ́ lãye, bi o ti ri li oni yi.
25 Yio si jẹ́ ododo wa, bi awa ba nṣọ́ ati
ma ṣe gbogbo ofin wọnyi niwaju Oluwa
Ọlọrun wa, bi o ti paṣẹ fun wa.

## ORI 7.

NIGBATI Oluwa Ọlọrun rẹ ba mú ọ dé
ilẹ na nibiti iwọ gbé nlọ lati gbà a, ti
o ba lé orilẹ-ède pupọ̀ kuro niwaju rẹ, awọn
Hitti, ati awọn Girgaṣi, ati awọn Amori,
ati awọn ara Kenaani, ati awọn Perissi, ati
awọn Hifi, ati awọn Jebusi, orilẹ-ède meje,
ti o pọ̀ ti o si lagbara jù ọ lọ;
2 Nigbati Oluwa Ọlọrun rẹ ba fi wọn lé
ọ lọwọ, iwọ o si kọlù wọn; ki o si run wọn
patapata; iwọ kò gbọdọ bá wọn dá majẹmu,
bẽni iwọ kò gbọdọ ṣãnu fun wọn:
3 Bẽni iwọ kò gbọdọ bá wọn dá ana;
ọmọbirin rẹ ni iwọ kò gbọdọ fi fun ọmọ-
kọnrin rẹ̀, ati ọmọbirin rẹ̀ ni iwọ kò gbọdọ
mú fun ọmọkọnrin rẹ.
4 Nitoripe nwọn o yi ọmọkọnrin rẹ pada
lati ma tọ̀ mi lẹhin, ki nwọn ki o le ma sìn
ọlọrun miran: ibinu Oluwa o si rú si nyin,
on a si run ọ lojiji.
5 Ṣugbọn bayi li ẹnyin o fi wọn ṣe;
ẹnyin o wó pẹpẹ wọn, ẹ o si bì ọwọ̀n wọn
lulẹ, ẹ o si ke igbo oriṣa wọn lulẹ, ẹ o si fi
iná jó gbogbo ere finfin wọn.
6 Nitoripe enia mimọ́ ni iwọ fun Oluwa
Ọlọrun rẹ: Oluwa Ọlọrun rẹ ti yàn ọ lati
jẹ́ enia ọ̀tọ fun ara rẹ̀, jù gbogbo enia lọ ti
mbẹ lori ilẹ.
7 Oluwa kò fi ifẹ́ rẹ̀ si nyin lara, bẽni
kò yàn nyin, nitoriti ẹnyin pọ̀ ni iye jù
awọn enia kan lọ; nitoripe ẹnyin li o tilẹ
kére jù ninu gbogbo enia:
8 Ṣugbọn nitoriti Oluwa fẹ́ nyin, ati
nitoriti on fẹ́ pa ara ti o ti bú fun awọn
baba nyin mọ́, ni Oluwa ṣe fi ọwọ́ agbara
mú nyin jade, o si rà nyin pada kuro li
oko-ẹrú, kuro li ọwọ́ Farao ọba Egipti.
9 Nitorina ki iwọ ki o mọ̀ pe, Oluwa
Ọlọrun rẹ, on li Ọlọrun; Ọlọrun olõtọ, ti
npa majẹmu mọ́ ati ãnu fun awọn ti o fẹ́
ẹ, ti nwọn si pa ofin rẹ̀ mọ́ dé ẹgbẹrun
iran;
10 Ti o si nsan a pada fun awọn ti o
korira rẹ̀ li oju wọn, lati run wọn: on ki
yio jafara fun ẹniti o korira rẹ̀, on o san a
fun u loju rẹ̀.
11 Nitorina ki iwọ ki o pa ofin ati ìlana,
ati idajọ mọ́, ti mo palaṣẹ fun ọ loni, lati
ma ṣe wọn.
12 Yio si ṣe, nitoriti ẹnyin fetisi idajọ
wọnyi, ti ẹ si npa wọn mọ́, ti ẹ si nṣe wọn,
njẹ Oluwa Ọlọrun rẹ yio ma pa majẹmu
ati ãnu mọ́ fun ọ, ti o ti bura fun awọn
baba rẹ:
13 On o si fẹ́ ọ, yio si bukún ọ, yio si
mu ọ bisi i: on o si bukún ọmọ inu rẹ, ati
eso ilẹ rẹ, ọkà rẹ, ati ọti-waini rẹ, ati oróro
rẹ, ibisi malu rẹ, ati awọn ọmọ agbo-agutan
rẹ, ni ilẹ na ti o ti bura fun awọn baba rẹ
lati fi fun ọ.
14 Iwọ o jẹ́ ẹni ibukún jù gbogbo enia
lọ: ki yio sí akọ tabi abo ninu nyin ti yio
yàgan, tabi ninu ohunọ̀sin nyin.
15 Oluwa yio si gbà àrun gbogbo kuro
lọdọ rẹ, ki yio si fi ọkan ninu àrun buburu
Egipti, ti iwọ mọ̀, si ọ lara, ṣugbọn on o fi
wọn lé ara gbogbo awọn ti o korira rẹ.
16 Iwọ o si run gbogbo awọn enia ti
Oluwa Ọlọrun rẹ yio fi fun ọ; oju rẹ kò
gbọdọ ṣãnu fun wọn: bẽni iwọ kò gbọdọ
sìn awọn oriṣa wọn; nitoripe idẹkùn li
eyinì yio jẹ́ fun ọ.
17 Bi iwọ ba wi li ọkàn rẹ pe, Awọn
orilẹ-ède wọnyi pọ̀ jù mi lọ; bawo li emi o
ṣe le lé wọn jade?
18 Ki iwọ ki o máṣe bẹ̀ru wọn: ṣugbọn
ki iwọ ki o ranti daradara ohun ti Oluwa
Ọlọrun rẹ ṣe si Farao, ati si gbogbo Egipti;
19 Idanwò nla ti oju rẹ ri, ati àmi, ati
iṣẹ-iyanu, ati ọwọ́ agbara, ati ninà apa, ti
Oluwa Ọlọrun rẹ fi mú ọ jade: bẽni Olu-
wa Ọlọrun rẹ yio ṣe si gbogbo awọn enia
na ẹ̀ru ẹniti iwọ mbà.
20 Pẹlupẹlu Oluwa Ọlọrun rẹ yio rán
agbọ́n sinu wọn, titi awọn ti o kù, ti nwọn
si fi ara wọn pamọ́ fun ọ yio fi run.
21 Ki iwọ ki o máṣe fòya wọn: nitoriti
Oluwa Ọlọrun rẹ mbẹ lãrin rẹ, Ọlọrun ti
o tobi ti o si lẹ̀ru.
22 Oluwa Ọlọrun rẹ yio tì awọn orilẹ-
ède na jade diẹdiẹ niwaju rẹ: ki iwọ ki o
máṣe run wọn tán lẹ̀kan, ki ẹranko igbẹ́ ki
o má ba pọ̀ si ọ.
23 Ṣugbọn Oluwa Ọlọrun rẹ yio fi wọn

Digitized by Google

lé ọ lọwọ, yio si fi iparun nla pa wọn run,
titi nwọn o fi run.
24 On o si fi awọn ọba wọn lé ọ lọwọ,
iwọ o si pa orukọ wọn run kuro labẹ ọrun:
kò sí ọkọnrin kan ninu wọn ti yio le duro
niwaju rẹ, titi iwọ o fi run wọn tán.
25 Ere finfin orișa wọn ni ki ẹnyin ki o
fi iná jó: iwọ kò gbọdọ ṣe ojukokoro fada-
kà tabi wurà ti mbẹ lara wọn, bẽni ki o
máṣe mú u fun ara rẹ, ki o má ba di idẹkùn
fun ọ; nitoripe ohun irira ni si OLUWA
Ọlọrun rẹ:
26 Bẽni iwọ kò gbọdọ mú ohun irira wá
sinu ile rẹ, ki iwọ ki o má ba di ẹni ifibú
bi rẹ̀: ṣugbọn ki iwọ ki o korira rẹ̀ pata-
pata, ki iwọ ki o si kà a si ohun irira pata-
pata; nitoripe ohun ìyasọtọ ni.

## ORI 8.

GBOGBO ofin ti mo palaṣẹ fun ọ li oni,
ni ki ẹnyin ma kiyesi lati ṣe, ki ẹnyin
ki o le yè, ki ẹnyin si ma pọ̀ si i, ki ẹnyin
si wọnu rẹ̀ lọ lati gbà ilẹ na ti OLUWA ti
bura fun awọn baba nyin.
2 Ki iwọ ki o si ranti ọ̀na gbogbo ti
OLUWA Ọlọrun rẹ ti mu ọ rìn li aginjù lati
ogoji ọdún yi wá, lati rẹ̀ ọ silẹ, ati lati dan
ọ wò, lati mọ̀ ohun ti o wà li àiya rẹ, bi
iwọ o pa ofin rẹ̀ mọ́, bi bẹ̃kọ.
3 O si rẹ̀ ọ silẹ, o si fi ebi pa ọ, o si fi
manna bọ́ ọ, ti iwọ kò mọ̀, bẽni awọn baba
rẹ kò mọ̀; ki o le mu ọ mọ̀ pe enia kò ti
ipa onjẹ nikan wà lãye, bikoṣe nipa gbo-
gbo ọ̀rọ ti o ti ẹnu OLUWA jade li enia wà
lãye.
4 Aṣọ rẹ kò gbó mọ́ ọ lara, bẹ̃li ẹsẹ̀ rẹ kò
wú, lati ogoji ọdún yi wá.
5 Ki iwọ ki o si mọ̀ li ọkàn rẹ pe, bi
enia ti ibá ọmọ rẹ̀ wi, bẽni OLUWA Ọlọrun
rẹ bá ọ wi.
6 Ki iwọ ki o pa ofin OLUWA Ọlọrun
rẹ mọ́, lati ma rìn li ọ̀na rẹ̀, ati lati ma
bẹru rẹ̀.
7 Nitori OLUWA Ọlọrun rẹ mú ọ wá sinu
ilẹ rere, ilẹ odò omi, ti orisun ati ti abẹ-ilẹ,
ti nrú soke lati afonifoji ati òke jade wa;
8 Ilẹ alikama ati ọkà-barle, ati àjara ati
igi ọpọtọ ati igi pomegranate; ilẹ oróro
olifi, ati oyin;
9 Ilẹ ninu eyiti iwọ ki o fi ìṣẹ jẹ onjẹ,
iwọ ki yio fẹ ohun kan kù ninu rẹ̀; ilẹ ti
okuta rẹ̀ iṣe irin, ati lati inu òke eyiti iwọ
o ma wà idẹ.
10 Nigbati iwọ ba si jẹun tán ti o si yo,
nigbana ni iwọ o fi ibukún fun OLUWA
Ọlọrun rẹ, nitori ilẹ rere na ti o fi fun ọ.
11 Ma kiyesara rẹ ki iwọ ki o má ṣe
gbagbé OLUWA Ọlọrun rẹ, li aipa ofin rẹ̀,
ati idajọ rẹ̀, ati ìlana rẹ̀ mọ́, ti mo filelẹ li
aṣẹ fun ọ li oni:
12 Ki iwọ ki o má ba jẹ yó tán, ki o kọ́
ile daradara, ki o si ma gbé inu rẹ̀;
13 Ati ki ọwọ́-ẹran rẹ ati agbo-ẹran rẹ,
ki o ma ba pọ̀si i tán, ki fadakà rẹ ati
wurà rẹ pọ̀si i, ati ki ohun gbogbo ti iwọ
ní pọ̀si i;
14 Nigbana ni ki ọkàn rẹ wa gbé soke,
iwọ a si gbagbé OLUWA Ọlọrun rẹ, ti o mú
ọ lati ilẹ Egipti jade wá, kuro li oko-ẹrú;
15 Ẹniti o mu ọ rìn aginjù nla ti o si li
ẹru, nibiti ejò amubĩna wà, ati akẽkẽ, ati
ọdá, nibiti omi kò sí; ẹniti o mú omi jade
fun ọ lati inu okuta akọ wá;
16 Ẹniti o fi manna bọ́ ọ li aginjù, ti
awọn baba rẹ kò mọ̀ rí; ki o le rẹ̀ ọ silẹ,
ki o le dan ọ wò, lati ṣe ọ li ore nigbẹhin
rẹ:
17 Iwọ a si wi li ọkàn rẹ pe, Agbara mi
ati ipa ọwọ́ mi li o fun mi li ọrọ̀ yi.
18 Ṣugbọn ki iwọ ki o ranti OLUWA
Ọlọrun rẹ; nitoripe, on li o fun ọ li agbara
lati lí ọrọ̀, ki on ki o le fi idi majẹmu rẹ̀ ti
o bura fun awọn baba rẹ kalẹ, bi o ti ri li
oni yi.
19 Yio si ṣe, bi iwọ ba gbagbé OLUWA
Ọlọrun rẹ, ti iwọ si tẹle ọlọrun miran, ti o
si nsìn wọn, ti o si mbọ wọn, emi tẹnumọ́
ọ fun nyin pe, rirun li ẹnyin o run.
20 Bi awọn orilẹ-ède ti OLUWA run kuro
niwaju nyin, bẹ̃li ẹnyin o run; nitoripe
ẹnyin ṣe àigbọran si ohùn OLUWA Ọlọrun
nyin.

## ORI 9.

GBỌ́, Israeli: iwọ o gòke Jordani li oni,
lati wọle lọ ìgba awọn orilẹ-ède ti o
tobi ti o si lagbara jù ọ lọ, ilu ti o tobi, ti
a mọdi rẹ̀ kàn ọrun,
2 Awọn enia ti o tobi ti o si sigbọnlẹ,
awọn ọmọ Anaki, ti iwọ mọ̀, ti iwọ si
gburó pe, Tali o le duro niwaju awọn ọmọ
Anaki?
3 Iwọ o si mọ̀ li oni pe, OLUWA Ọlọrun
rẹ on ni ngòke ṣaju rẹ lọ bi iná ajonirun;
yio pa wọn run, on o si rẹ̀ wọn silẹ niwaju
rẹ: iwọ o si lé wọn jade, iwọ o si pa wọn
run kánkán, bi OLUWA ti wi fun ọ.
4 Máṣe sọ li ọkàn rẹ, lẹhin igbati OLU-
WA Ọlọrun rẹ ba tì wọn jade kuro niwaju
rẹ, wipe, Nitori ododo mi ni OLUWA ṣe
mú mi wá lati gbà ilẹ yi: ṣugbọn nitori



Digitized by Google

ìwabuburu awọn orilẹ-ède wọnyi ni OLUWA ṣe lé wọn jade kuro niwaju rẹ.

5 Ki iṣe nitori ododo rẹ, tabi nitori pipé ọkàn rẹ, ni iwọ fi nlọ lati gbà ilẹ wọn: ṣugbọn nitori ìwabuburu awọn orilẹ-ède wọnyi li OLUWA Ọlọrun rẹ ṣe lé wọn kuro niwaju rẹ, ati ki o le mu ọ̀rọ na ṣẹ ti OLUWA ti bura fun awọn baba rẹ, Abrahamu, Isaaki, ati Jakobu.

6 Nitorina ki o yé ọ pe, OLUWA Ọlọrun rẹ kò fi ilẹ rere yi fun ọ lati ní i nitori ododo rẹ; nitoripe enia ọlọrùn lile ni iwọ.

7 Ranti, máṣe gbagbé, bi iwọ ti mu OLUWA Ọlọrun rẹ binu li aginjù: lati ọjọ́ na ti iwọ ti jade kuro ni ilẹ Egipti, titi ẹnyin fi dé ihin yi, ẹnyin ti nṣọ̀tẹ si OLUWA.

8 Ati ni Horebu ẹnyin mu OLUWA binu, OLUWA si binu si nyin tobẽ ti o fẹ́ pa nyin run.

9 Nigbati mo gòke lọ sori òke lati gbà walã okuta wọnni, ani walã majẹmu ní ti OLUWA bá nyin dá, nigbana mo gbé ogoji ọsán, ati ogoji oru lori òke na, emi kò jẹ onjẹ, bẽli emi kò mu omi.

10 OLUWA si fi walã okuta meji fun mi, ti a fi ika Ọlọrun kọ; ati lara wọn li a kọ ọ gẹgẹ bi gbogbo ọ̀rọ na, ti OLUWA bá nyin sọ li òke na lati inu ãrin iná wá li ọjọ́ ajọ nì.

11 O si ṣe li opin ogoji ọsán ati ogoji oru, ti OLUWA fi walã okuta meji nì fun mi, ani walã majẹmu nì.

12 OLUWA si wi fun mi pe, Dide, sọkalẹ kánkán lati ihin lọ; nitoriti awọn enia rẹ, ti iwọ mú lati ilẹ Egipti jade wá, ti bà ara wọn jẹ́; nwọn yipada kánkán kuro li ọ̀na ti mo palaṣẹ fun wọn; nwọn ti yá ere didà fun ara wọn.

13 OLUWA sọ fun mi pẹlu pe, Emi ti ri enia yi, si kiyesi i, enia ọlọrùn lile ni:

14 Yàgo fun mi, ki emi ki o pa wọn run, ki emi si pa orukọ wọn rẹ́ kuro labẹ ọrun: emi o si sọ iwọ di orilẹ-ède ti o lagbara ti o si pọ̀ jù wọn lọ.

15 Emi si pada, mo si sọkalẹ lati ori òke nì wá, òke na si njóna: walã meji ti majẹmu nì si wà li ọwọ́ mi mejeji.

16 Mo si wò, si kiyesi i, ẹnyin ti ṣẹ̀ si OLUWA Ọlọrun nyin, ẹnyin si ti yá ẹgbọrọ-malu didà fun ara nyin: ẹnyin ti yipada kánkán kuro li ọ̀na ti OLUWA ti palaṣẹ fun nyin.

17 Emi si mú walã meji nì, mo si sọ wọn silẹ kuro li ọwọ́ mi mejeji, mo si fọ́ wọn niwaju nyin.

18 Emi si wolẹ niwaju OLUWA bi ti iṣaju, li ogoji ọsán ati ogoji oru; emi kò jẹ onjẹ, bẽli emi kò mu omi; nitori gbogbo ẹ̀ṣẹ nyin ti ẹnyin ṣẹ̀, ni ṣiṣe buburu li oju OLUWA, lati mu u binu.

19 Nitoriti emi bẹ̀ru ibinu ati irunu OLUWA si nyin lati pa nyin run. OLUWA si gbọ́ ti emi nigbana pẹlu.

20 OLUWA si binu si Aaroni gidigidi ti iba fi pa a run: emi si gbadurá fun Aaroni nigbana pẹlu.

21 Emi si mú ẹ̀ṣẹ nyin, ẹgbọrọ-malu ti ẹnyin ṣe, mo si fi iná sun u, mo si gún u, mo si lọ̀ ọ kúnna, titi o fi dabi ekuru: mo si kó ekuru rẹ̀ lọ idà sinu odò ti o ti òke na ṣànwalẹ.

22 Ati ni Tabera, ati ni Massa, ati ni Kibrotu-hattaafa, ẹnyin mu OLUWA binu.

23 Nigbati OLUWA rán nyin lati Kadeṣi-barnea lọ, wipe, Gòke lọ ki o si gbà ilẹ na ti mo fi fun nyin; nigbana li ẹnyin ṣọ̀tẹ si aṣẹ OLUWA Ọlọrun nyin, ẹnyin kò si gbà a gbọ́, bẽli ẹnyin kò si fetisi ohùn rẹ̀.

24 Ẹnyin ti nṣọ̀tẹ si OLUWA lati ọjọ́ ti mo ti mọ̀ nyin.

25 Mo si wolẹ niwaju OLUWA li ogoji ọsán ati li ogoji oru, bi mo ti wolẹ niṣaju; nitoriti OLUWA wipe, on o run nyin.

26 Mo si gbadura sọdọ OLUWA wipe, Oluwa ỌLỌRUN, máṣe run awọn enia rẹ ati iní rẹ, ti iwọ ti fi titobi rẹ ràsilẹ, ti iwọ mú lati Egipti jade wá pẹlu ọwọ́ agbara.

27 Ranti Abrahamu, Isaaki, ati Jakobu awọn iranṣẹ rẹ; máṣe wò agídi awọn enia yi, tabi ìwabuburu wọn, tabi ẹ̀ṣẹ wọn:

28 Ki awọn enia ilẹ na ninu eyiti iwọ ti mú wa jade wá ki o má ba wipe, Nitoriti OLUWA kò le mú wọn dé ilẹ na ti o ti ṣe ileri fun wọn, ati nitoriti o korira wọn, li o ṣe mú wọn jade wá lati pa wọn li aginjù.

29 Ṣugbọn sibẹ̀ enia rẹ ni nwọn iṣe, ati iní rẹ, ti iwọ mú jade nipa agbara nla rẹ, ati nipa ninà apa rẹ.

## ORI 10.

NIGBANA li OLUWA wi fun mi pe, Gbẹ́ walã okuta meji bi ti iṣaju, ki o si tọ̀ mi wá lori òke na, ki o si ṣe apoti igi kan.

2 Emi o si kọ ọ̀rọ ti o ti wà lara walã iṣaju ti iwọ fọ́, sara walã wọnyi, iwọ o si fi wọn sinu apoti na.

3 Emi si ṣe apoti igi ṣittimu kan, mo si gbẹ́ walã okuta meji bi ti iṣaju, mo si lọ sori òke na, walã mejeji si wà li ọwọ́ mi.

4 On si kọ ofin mẹwẹwa sara walã wọnni, gẹgẹ bi o ti kọ ti iṣaju, ti OLUWA sọ

Digitized by Google

fun nyin lori òke na lati inu ãrin iná wá li
ọjọ́ ajọ nì: Oluwa si fi wọn fun mi.
5 Mo si pada, mo si sọkalẹ lati ori òke
na wá, mo si fi walã wọnni sinu apoti ti
mo ti ṣe; nwọn si wà nibẹ̀, bi Oluwa ti
paṣẹ fun mi.
6 (Awọn ọmọ Israeli si dide ìrin wọn
lati Beerotu ti iṣe ti awọn ọmọ Jaakani lọ
si Mosera: nibẹ̀ li Aaroni gbé kú, nibẹ̀ li a
si sin i; Eleasari ọmọ rẹ̀ si nṣe iṣẹ alufa
ni ipò rẹ̀.
7 Lati ibẹ̀ nwọn si lọ si Gudgoda; ati
lati Gudgoda lọ si Jotbati, ilẹ olodò omi.
8 Nigbana li Oluwa yà ẹ̀ya Lefi sọ̀tọ,
lati ma rù apoti majẹmu Oluwa, lati ma
duro niwaju Oluwa lati ma ṣe iranṣẹ fun
u, ati lati ma sure li orukọ rẹ̀, titi di oni yi.
9 Nitorina ni Lefi kò ṣe ní ipín tabi iní
pẹlu awọn arakọ̀nrin rẹ̀; Oluwa ni iní rẹ̀,
gẹgẹ bi Oluwa Ọlọrun ti ṣe ileri fun u.)
10 Emi si duro lori òke na gẹgẹ bi ìgba
iṣaju, li ogoji ọsán ati ogoji oru: Oluwa
si gbọ́ ti emi ni igbana pẹlu, Oluwa kò si
fẹ́ run ọ.
11 Oluwa si wi fun mi pe, Dide, mú
ọ̀na ìrin rẹ niwaju awọn enia, ki nwọn ki
o le wọ̀ inu rẹ̀ lọ, ki nwọn ki o le gbà ilẹ
na, ti mo ti bura fun awọn baba wọn lati
fi fun wọn.
12 Njẹ nisisiyi, Israeli, kini Oluwa
Ọlọrun rẹ mbère lọdọ rẹ, bikoṣe lati ma
bẹ̀ru Oluwa Ọlọrun rẹ, lati ma rìn li ọ̀na
rẹ̀ gbogbo, lati ma fẹ́ ẹ, ati lati ma sìn
Oluwa Ọlọrun rẹ pẹlu àiya rẹ gbogbo, ati
pẹlu ọkàn rẹ gbogbo,
13 Lati ma pa ofin Oluwa mọ́, ati ìlana
rẹ̀, ti mo filelẹ fun ọ li aṣẹ li oni, fun
ire rẹ?
14 Kiyesi i, ti Oluwa Ọlọrun rẹ li ọrun,
ati ọrun dé ọrun, aiye pẹlu, ti on ti ohun
gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀.
15 Kìki Oluwa ni inudidùn si awọn
baba rẹ lati fẹ́ wọn, on si yàn irú-ọmọ wọn
lẹhin wọn, ani ẹnyin jù gbogbo enia lọ, bi
o ti ri li oni yi.
16 Nitorina ẹ kọ àiya nyin nilà, ki ẹ má
si ṣe ọlọrùn lile mọ́.
17 Nitori Oluwa Ọlọrun nyin, Ọlọrun
awọn ọlọrun ni, ati Oluwa awọn oluwa,
Ọlọrun titobi, alagbara, ati ẹlẹrù, ti ki iṣe
ojusaju, bẽni ki igba abẹtẹlẹ.
18 On ni ima ṣe idajọ alainibaba ati opó,
o si fẹ́ alejò, lati fun u li onjẹ ati aṣọ.
19 Nitorina ki ẹnyin ki o ma fẹ́ alejò:
nitoripe ẹnyin ṣe alejò ni ilẹ Egipti.
20 Ki iwọ ki o ma bẹ̀ru Oluwa Ọlọrun
rẹ; on ni ki iwọ ki o ma sìn, on ni ki iwọ
ki o si faramọ́, orukọ rẹ̀ ni ki o si ma fi
bura.
21 On ni iyìn rẹ, on si li Ọlọrun rẹ, ti o
ṣe ohun nla ati ohun ẹlẹrù wọnni fun ọ, ti
oju rẹ ri.
22 Awọn baba rẹ sọkalẹ lọ si Egipti
ti awọn ti ãdọrin enia; ṣugbọn nisisiyi
Oluwa Ọlọrun rẹ sọ ọ dabi irawọ ọrun
li ọ̀pọlọpọ.

## ORI 11.

NITORINA ki iwọ ki o fẹ́ Oluwa Ọlọrun
rẹ, ki o si ma pa ìlọ rẹ̀, ati ìlana rẹ̀,
ati idajọ rẹ̀, ati ofin rẹ̀ mọ́, nigbagbogbo.
2 Ki ẹnyin ki o si mọ̀ li oni: nitoripe
awọn ọmọ nyin ki emi nsọ fun ti kò mọ̀, ti
kò si ri ibawi Oluwa Ọlọrun nyin, titobi
rẹ̀, ọwọ́ agbara rẹ̀, ati ninà apa rẹ̀,
3 Ati iṣẹ-àmi rẹ̀, ati iṣẹ rẹ̀, ti o ṣe lãrin
Egipti, si Farao ọba Egipti, ati si gbogbo
ilẹ rẹ̀;
4 Ati ohun ti o ṣe si ogun Egipti, si ẹṣin
wọn, ati kẹkẹ́-ogun wọn; bi o ti mu ki
omi Okun Pupa bò wọn mọlẹ bi nwọn ti
nlepa nyin lọ, ati bi Oluwa ti run wọn
titi di oni-oloni;
5 Ati bi o ti ṣe si nyin li aginjù, titi
ẹnyin fi dé ihin yi;
6 Ati bi o ti ṣe si Datani ati Abiramu,
awọn ọmọ Eliabu, ọmọ Reubeni; bi ilẹ ti
yà ẹnu rẹ̀, ti o si gbe wọn mì, ati ara ile
wọn, ati agọ́ wọn, ati ohun alãye gbogbo ti
o tẹle wọn, lãrin gbogbo Israeli:
7 Ṣugbọn oju nyin ti ri gbogbo iṣẹ nla
Oluwa ti o ṣe.
8 Nitorina ki ẹnyin ki o pa gbogbo ofin
mọ́ ti mo filelẹ li aṣẹ fun nyin li oni, ki
ẹnyin ki o le lagbara, ki ẹnyin ki o si wọ̀
inu rẹ̀ lọ, ki ẹ si gbà ilẹ na, nibiti ẹnyin
nlọ lati gbà a;
9 Ati ki ẹnyin ki o le mu ọjọ́ nyin pẹ ni
ilẹ na, ti Oluwa ti bura fun awọn baba
nyin, lati fi fun wọn ati fun irú-ọmọ wọn,
ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin.
10 Nitoripe ilẹ na, nibiti iwọ nlọ lati
gbà a, kò dabi ilẹ Egipti, nibiti ẹnyin ti
jade wá, nibiti iwọ gbìn irugbìn rẹ, ti iwọ
si nfi ẹsẹ̀ rẹ bomirin i, bi ọgbà ewebẹ̀:
11 Ṣugbọn ilẹ na, nibiti ẹnyin nlọ lati
gbà a, ilẹ òke ati afonifoji ni, ti o si nmu
omi òjo ọrun:
12 Ilẹ ti Oluwa Ọlọrun rẹ nṣe itọju;
oju Oluwa Ọlọrun rẹ mbẹ lara rẹ̀ nigba-
gbogbo, lati ìbẹrẹ ọdún dé opin ọdún.
13 Yio si ṣe, bi ẹnyin ba fetisi ofin mi

Digitized by Google

daradara, ti mo filelẹ li aṣẹ fun nyin li oni,
lati ma fẹ́ OLUWA Ọlọrun nyin, ati lati ma
sìn i pẹlu àiya nyin gbogbo, ati pẹlu ọkàn
nyin gbogbo,
14 Nigbana li emi o ma fun nyin li òjo
ilẹ nyin li akokò rẹ̀, òjo akọ́rọ̀ ati òjo àrọ-
kuro, ki iwọ ki o le ma kó ọkà rẹ, ati ọti-
waini rẹ, ati oróro rẹ sinu ile.
15 Emi o si fi koriko sinu pápa rẹ
fun ohunọ̀sin rẹ, ki iwọ ki o le jẹun ki o
si yó.
16 Ẹ ma ṣọ́ ara nyin, ki a má ba tàn
àiya nyin jẹ, ki ẹ má si ṣe yapa, ki ẹ si sìn
ọlọrun miran, ki ẹ si ma bọ wọn ;
17 Ibinu OLUWA a si rú si nyin, on a si
sé ọrun, ki òjo ki o má ba sí, ati ki ilẹ
ki o má ba so eso rẹ̀ ; ẹnyin a si run kán-
kán kuro ni ilẹ rere na ti OLUWA fi fun
nyin.
18 Ẹ fi ọ̀rọ mi wọnyi si àiya nyin ati si
ọkàn nyin, ki ẹ si so wọn mọ́ ọwọ́ nyin
fun àmi, ki nwọn ki o si ma ṣe ọjá-igbaju
niwaju nyin.
19 Ki ẹnyin ki o si ma fi wọn kọ́ awọn
ọmọ nyin, ki ẹnyin ma fi wọn ṣe ọ̀rọ isọ
nigbati iwọ ba joko ninu ile rẹ, ati nigbati
iwọ ba nrìn li ọ̀na, nigbati iwọ ba dubulẹ,
ati nigbati iwọ ba dide.
20 Ki iwọ ki o si kọ wọn sara opó ile rẹ,
ati sara ilẹkun-ọ̀na-ode rẹ ;
21 Ki ọjọ́ nyin ki o le ma pọ̀si i, ati ọjọ́
awọn ọmọ nyin, ni ilẹ na ti OLUWA bura
fun awọn baba nyin lati fi fun wọn, bi ọjọ́
ọrun lori ilẹ aiye.
22 Nitoripe bi ẹnyin ba pa gbogbo ofin
yi mọ́ gidigidi, ti mo palaṣẹ fun nyin, lati
ma ṣe e ; lati ma fẹ́ OLUWA Ọlọrun nyin,
lati ma rìn ni gbogbo ọ̀na rẹ̀, ati lati
faramọ́ ọ ;
23 Nigbana ni OLUWA yio lé gbogbo
awọn orilẹ-ède wọnyi jade kuro niwaju
nyin, ẹnyin o si gbà orilẹ-ède ti o tobi ti o
si lagbara jù nyin lọ.
24 Ibi gbogbo ti atẹlẹsẹ̀ nyin ba tẹ̀ yio
jẹ́ ti nyin : lati aginjù nì, ati Lebanoni, lati
odò nla nì, odò Euferate, ani dé ikẹhin
okun ni yio jẹ́ opinlẹ nyin.
25 Kò sí ọkọnrin kan ti yio le duro ni-
waju nyin : OLUWA Ọlọrun nyin, yio fi
ìbẹru nyin ati ìfoya nyin sara gbogbo ilẹ ti
ẹnyin o tẹ̀, bi on ti wi fun nyin.
26 Wò o, emi fi ibukún ati egún siwaju
nyin li oni ;
27 Ibukún, bi ẹnyin ba gbà ofin OLUWA
Ọlọrun nyin gbọ́, ti mo palaṣẹ fun nyin li
oni :
28 Ati egún, bi ẹnyin kò ba gbà ofin
OLUWA Ọlọrun nyin gbọ́ ti ẹnyin ba si yi-
pada kuro li ọ̀na ti mo palaṣẹ fun nyin li
oni, lati ma tọ̀ ọlọrun miran lẹhin, ti ẹnyin
kò mọ̀ rí.
29 Yio si ṣe, nigbati OLUWA Ọlorun rẹ
ba mú ẹ dé ilẹ na, nibiti iwọ nlọ lati gbà a,
ki iwọ ki o ma sure lori òke Gerisimu, ki
iwọ ki o si ma gegun lori òke Ebali.
30 Awọn kọ ha wà ni ìha keji Jordani,
li ọ̀na ìwọ-õrùn, ni ilẹ awọn ara Kenaani,
ti ngbé Araba ti o kọjusi Gilgali, lẹba igbó
More ?
31 Nitoripe ẹnyin o gòke Jordani lati
wọle ati lati gbà ilẹ na, ti OLUWA Ọlọrun
nyin fi fun nyin, ẹnyin o si gbà a, ẹnyin o
si ma gbé inu rẹ̀.
32 Ki ẹnyin ki o si ma kiyesi ati ma ṣe
gbogbo ìlana ati idajọ wọ̀nni, ti mo fi si-
waju nyin li oni.

## ORI 12.

WỌNYI ni ìlana ati idajọ, ti ẹnyin o ma
kiyesi lati ma ṣe ni ilẹ na ti OLUWA,
Ọlọrun awọn baba rẹ fi fun ọ lati ní, ni
gbogbo ọjọ́ ti ẹnyin o wà lori ilẹ-aiye.
2 Ki ẹnyin ki o run ibi gbogbo wọnni
patapata, nibiti awọn orilẹ-ède nì, ti ẹnyin
o gbà, nsìn oriṣa wọn, lori òke giga, ati
lori òke kekeké, ati labẹ igi tutù gbogbo :
3 Ki ẹnyin ki o si wó pẹpẹ wọn, ki ẹ si
bì ọwọ̀n wọn ṣubu, ki ẹ si fi iná kun igbo
oriṣa wọn ; ki ẹnyin ki o si ke ere fifin
wọn lulẹ, ki ẹ si run orukọ wọn kuro ni
ibẹ na.
4 Ẹnyin kò gbọdọ ṣe bẹ̃ si OLUWA Ọlọrun
nyin.
5 Ṣugbọn ibi ti OLUWA Ọlorun nyin yio
yàn ninu gbogbo ẹ̀ya nyin lati fi orukọ rẹ̀
si, ani ibujoko rẹ̀ li ẹnyin o ma wálọ, ati
nibẹ̀ ni ki iwọ ki o ma wá :
6 Nibẹ̀ ni ki ẹnyin ki o ma mú ẹbọ sisun
nyin wá, ati ẹbọ nyin, ati idamẹwa nyin,
ati ẹbọ igbesọsoke ọwọ́ nyin, ati ẹjẹ́ nyin,
ati ẹbọ ifẹ́-atinuwa nyin, ati akọ́bi ọwọ́-ẹran
nyin ati ti agbo-ẹran nyin :
7 Nibẹ̀ ni ki ẹnyin ki o si ma jẹ niwaju
OLUWA Ọlọrun nyin, ki ẹnyin ki o si ma
yọ̀ ninu ohun gbogbo ti ẹnyin fi ọwọ́ nyin
lé, ẹnyin ati awọn ara ile nyin, ninu eyiti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi bukún u fun ọ.
8 Ki ẹnyin ki o máṣe ṣe gẹgẹ bi gbogbo
ohun ti awa nṣe nihin li oni, olukuluku
enia ohun ti o tọ́ li oju ara rẹ̀ :
9 Nitoripe ẹnyin kò sá ti idé ibi-isimi,

Digitized by Google

ati ilẹ iní, ti Oluwa Ọlọrun nyin fi fun
nyin.
10 Ṣugbọn nigbati ẹnyin ba gòke Jor-
dani, ti ẹnyin si joko ni ilẹ na ti Oluwa
Ọlọrun nyin fi fun nyin ni iní, ti o ba si
fun nyin ni isimi kuro lọwọ awọn ọtá nyin
gbogbo yiká, ti ẹnyin si joko li alafia:
11 Nigbana ni ibikan yio wà ti Oluwa
Ọlọrun nyin yio yàn lati fi orukọ rẹ̀ si, nibẹ̀
li ẹnyin o ma mú gbogbo ohun ti mo palaṣẹ
fun nyin wá; ẹbọ sisun nyin, ati ẹbọ nyin,
idamẹwa nyin, ati ẹbọ igbesọsoke ọwọ nyin,
ati gbogbo àṣayan ẹjẹ́ nyin ti ẹnyin jẹ́ fun
Oluwa.
12 Ki ẹnyin ki o si ma yọ̀ niwaju Oluwa
Ọlọrun nyin, ẹnyin, ati awọn ọmọ nyin
ọkọnrin, ati awọn ọmọ nyin obirin, ati
awọn ọmọ-ọdọ nyin ọkọnrin, ati awọn ọmọ-
ọdọ nyin obirin, ati ọmọ Lefi ti mbẹ ninu
ibode nyin, nitori on kò ní ipín tabi iní
pẹlu nyin.
13 Ma ṣọ́ ara rẹ ki iwọ ki o máṣe ru ẹbọ
sisun rẹ ni ibi gbogbo ti iwọ ba ri:
14 Bikoṣe ni ibi ti Oluwa yio yàn ninu
ọkan ninu awọn ẹ̀ya rẹ, nibẹ̀ ni ki iwọ ki o
ma ru ẹbọ sisun rẹ, nibẹ̀ ni ki iwọ ki o si
ma ṣe ohun gbogbo ti mo palaṣẹ fun ọ.
15 Ṣugbọn ki iwọ ki o ma pa, ki o si ma
jẹ ẹran ninu ibode rẹ gbogbo, ohunkohun
ti ọkàn rẹ ba fẹ́, gẹgẹ bi ibukún Oluwa
Ọlọrun rẹ ti o fi fun ọ: alaimọ́ ati ẹni mi-
mọ́ ni ki o ma jẹ ninu rẹ̀, bi esuwo, ati bi
agbọnrin.
16 Kìki ẹ̀jẹ li ẹnyin kò gbọdọ jẹ; lori
ilẹ ni ki ẹ dà a si bi omi.
17 Ki iwọ ki o máṣe jẹ idamẹwa ọkà rẹ
ninu ibode rẹ, tabi ti ọti-waini rẹ, tabi ti
oróro rẹ, tabi ti akọ́bi ọwọ́-ẹran rẹ, tabi ti
agbo-ẹran rẹ, tabi ti ẹjẹ́ rẹ ti iwọ jẹ́, tabi
ẹbọ ifẹ́-atinuwa rẹ, tabi ẹbọ igbesọsoke
ọwọ́ rẹ:
18 Bikoṣe ki iwọ ki o jẹ wọn niwaju
Oluwa Ọlọrun rẹ, ni ibi ti Oluwa Ọlọrun
rẹ yio gbé yàn, iwọ, ati ọmọ rẹ ọkọnrin,
ati ọmọ rẹ obirin, ati ọmọ-ọdọ rẹ ọkọnrin,
ati ọmọ-ọdọ rẹ obirin, ati ọmọ Lefi ti mbẹ
ninu ibode rẹ: ki iwọ ki o si ma yọ̀ niwaju
Oluwa Ọlọrun rẹ ninu ohun gbogbo ti iwọ
fi ọwọ́ rẹ lé.
19 Ma ṣọ́ ara rẹ ki iwọ ki o máṣe kọ̀ ọmọ
Lefi silẹ ni gbogbo ọjọ́ rẹ lori ilẹ.
20 Nigbati Oluwa Ọlọrun rẹ ba sọ
àgbegbe rẹ di nla, bi on ti ṣe ileri fun ọ, ti
iwọ ba si wipe, Emi o jẹ ẹran, nitoriti ọkàn
rẹ nfẹ́ ẹran ijẹ; ki iwọ ki o ma jẹ ẹran,
ohunkohun ti ọkàn rẹ ba nfẹ́.
21 Bi o ba ṣepe, ibi ti Oluwa Ọlọrun
rẹ ba yàn, lati fi orukọ rẹ̀ si, ba jìna jù fun
ọ, njẹ ki iwọ ki o pa ninu ọwọ́-ẹran rẹ ati
ninu agbo-ẹran rẹ, ti Oluwa fi fun ọ, bi
emi ti fi aṣẹ fun ọ, ki iwọ ki o si ma jẹ
ohunkohun ti ọkàn rẹ ba fẹ́ ninu ibode rẹ.
22 Ani bi ã ti ijẹ esuwo, ati agbọnrin,
bẹ̃ni ki iwọ ki o ma jẹ wọn: alaimọ́ ati ẹni
mimọ́ yio jẹ ninu wọn bakanna.
23 Kìki ki o ṣọ́ ara rẹ gidigidi ki iwọ ki
o màṣe jẹ ẹ̀jẹ: nitoripe ẹ̀jẹ li ẹmi; iwọ kò
si gbọdọ jẹ ẹmi pẹlu ẹran.
24 Iwọ kò gbọdọ jẹ ẹ; iwọ o dà a silẹ bi
omi.
25 Iwọ kò gbọdọ jẹ ẹ; ki o le ma dara
fun ọ, ati fun awọn ọmọ rẹ lẹhin rẹ, nigbati
iwọ ba nṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa.
26 Kìki ohun mimọ́ rẹ ti iwọ ní, ati ẹjẹ́
rẹ ni ki iwọ ki o mú, ki o si lọ si ibi ti
Oluwa yio yàn:
27 Ki iwọ ki o si ma ru ẹbọ sisun rẹ,
ẹran ati ẹ̀jẹ na, lori pẹpẹ Oluwa Ọlọrun
rẹ: ati ẹ̀jẹ ẹbọ rẹ ni ki a dà sori pẹpẹ
Oluwa Ọlọrun rẹ, ki iwọ ki o si ma jọ
ẹran na.
28 Kiyesara ki o si ma gbọ́ gbogbo ọ̀rọ
wọnyi ti mo palaṣẹ fun ọ, ki o le dara fun
ọ, ati fun awọn ọmọ rẹ lẹhin rẹ lailai, ni-
gbati iwọ ba ṣe eyiti o dara ti o si tọ́ li oju
Oluwa Ọlọrun rẹ.
29 Nigbati Oluwa Ọlọrun rẹ ba ké awọn
orilẹ-ède wọnni kuro niwaju rẹ, nibiti iwọ
gbé nlọ lati gbà wọn, ti iwọ si rọpò wọn, ti
iwọ si joko ni ilẹ wọn;
30 Ma ṣọ́ ara rẹ ki iwọ má ba bọ́ si idẹ-
kùn ati tẹle wọn lẹhin, lẹhin igbati a ti run
wọn kuro niwaju rẹ; ki iwọ ki o má si
bère oriṣa wọn, wipe, Bawo li awọn orilẹ-
ède wọnyi ti nsìn oriṣa wọn? emi o si ṣe
bẹ̃ pẹlu.
31 Iwọ kò gbọdọ ṣe bẹ̃ si Oluwa Ọlọrun
rẹ; nitoripe gbogbo ohun irira si Oluwa,
ti on korira ni nwọn ti nṣe si awọn oriṣa
wọn; nitoripe awọn ọmọkọnrin, ati awọn
ọmọbirin wọn pẹlu ni nwọn nsun ninu iná
fun oriṣa wọn.
32 Ohunkohun ti mo filelẹ li aṣẹ fun
nyin, ẹ ma kiyesi lati ṣe e: iwọ kò gbọdọ
bukún u, bẹ̃ni iwọ kò gbọdọ bù kuro
ninu rẹ̀.

## ORI 13.

BI wolĩ kan ba hù lãrin rẹ, tabi alalá kan,
ti o si fi àmi tabi iṣẹ-iyanu kan
hàn ọ,
2 Ti àmi na tabi iṣẹ-iyanu na ti o sọ

Digitized by Google

fun ọ ba ṣẹ, wipe, Ẹ jẹ ki a tẹle ọlọrun
miran lẹhin, ti iwọ kò ti mọ̀ rí, ki a si ma
sìn wọn;
3 Iwọ kò gbọdọ fetisi ọ̀rọ woli na, tabi
alalá na: nitoripe OLUWA Ọlọrun nyin
ndan nyin wò ni, lati mọ̀ bi ẹnyin ba fi
gbogbo àiya nyin, ati gbogbo ọkàn nyin fẹ́
OLUWA Ọlọrun nyin.
4 Lẹhin OLUWA Ọlọrun nyin ni ki ẹnyin
ki o ma rìn, on ni ki ẹ si ma bẹ̀ru, ki ẹ si
ma pa ofin rẹ̀ mọ́, ki ẹ si ma gbà ohùn rẹ̀
gbọ́, ki ẹ si ma sìn i, ki ẹ si ma faramọ́ ọ.
5 Ati woli na, tabi alalá na, ni ki ẹnyin
ki o pa; nitoriti o ti sọ ìṣọtẹ si OLUWA
Ọlọrun nyin, ti o mú nyin lati ilẹ Egipti
jade wá, ti o ti rà nyin kuro li oko-ẹrú,
lati tì ọ kuro li oju ọ̀na ti OLUWA Ọlọrun
rẹ filelẹ li aṣẹ fun ọ lati ma rìn ninu rẹ̀.
Bẹ̃ni ki iwọ ki o si mú ibi kuro lãrin rẹ.
6 Bi arakọnrin rẹ, ọmọ iya rẹ, tabi ọmọ
rẹ ọkọnrin, tabi ọmọ rẹ obirin, tabi aya
õkan-àiya rẹ, tabi ọrẹ́ rẹ, ti o dabi ọkàn
ara rẹ, bi o ba tàn ọ ni ìkọkọ, wipe, Jẹ ki
a lọ ki a ma sìn ọlọrun miran, ti iwọ kò
mọ̀ rí, iwọ, tabi awọn baba rẹ;
7 Ninu awọn oriṣa awọn enia ti o yi
nyin kakiri ti o sunmọ ọ, tabi ti o jìna si ọ,
lati opin ilẹ dé opin ilẹ;
8 Iwọ kò gbọdọ jẹ fun u, bẹ̃ni iwọ kò
gbọdọ fetisi tirẹ̀; bẹ̃ni ki oju ki o máṣe
ro ọ, bẹ̃ni ki iwọ ki o máṣe da a si, bẹ̃ni ki
iwọ ki o máṣe bò o:
9 Ṣugbọn pipa ni ki o pa a; ọwọ́ rẹ ni
yio kọ́ wà lara rẹ̀ lati pa a, ati lẹhin na ọwọ́
gbogbo enia.
10 Ki iwọ ki o si sọ ọ li okuta, ki o kú;
nitoriti o nwá ọ̀na lati tì ọ kuro lọdọ OLUWA
Ọlọrun rẹ, ti o mú ọ lati ilẹ Egipti jade
wá, kuro li oko-ẹrú.
11 Gbogbo Israeli yio si gbọ́, nwọn o si
bẹ̀ru, nwọn ki o si tun hù ìwabuburu bi irú
eyi mọ́ lãrin nyin.
12 Bi iwọ ba gbọ́ ninu ọkan ninu awọn
ilu rẹ, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ lati ma
gbé inu rẹ̀ pe,
13 Awọn ọkọnrin kan, awọn ọmọ Beliali,
nwọn jade lọ kuro ninu nyin, nwọn si kó
awọn ara ilu wọn sẹhin, wipe, Ẹ jẹ ki a
lọ ki a ma sìn ọlọrun miran, ti ẹnyin kò
mọ̀ rí.
14 Nigbana ni ki iwọ ki o bère, ki iwọ
ki o si ṣe àwári, ki o si bère pẹlẹpẹlẹ; si
kiyesi i, bi o ba ṣe otitọ, ti ohun na ba si
da nyin loju, pe a ṣe irú nkan irira bẹ̃ ninu
nyin;
15 Ki iwọ ki o fi oju idà kọlù awọn ara
ilu na nitõtọ, lati run u patapata, ati ohun
gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀, ati ohunọ̀sin inu rẹ̀,
ni ki iwọ ki o fi oju idà pa.
16 Ki iwọ ki o si kó gbogbo ikogun rẹ̀
si ãrin igboro rẹ̀, ki iwọ ki o si fi iná kun
ilu na, ati gbogbo ikogun rẹ̀ patapata fun
OLUWA Ọlọrun rẹ: ki o si ma jasi òkiti
lailai; a ki yio si tun tẹ̀ ẹ dó mọ́.
17 Ki ọkan ninu ohun ìyasọtọ na má si
ṣe mọ́ ọ lọwọ; ki OLUWA ki o le yipada
kuro ninu imuna ibinu rẹ̀, ki o si ma ṣãnu
fun ọ, ki o si ma ṣe iyọnu rẹ, ki o si ma mu
ọ bisi i, bi o ti bura fun awọn baba rẹ;
18 Nigbati iwọ ba fetisi ohùn OLUWA
Ọlọrun rẹ, lati pa gbogbo ofin rẹ̀ mọ́, ti mo
palaṣẹ fun ọ li oni, lati ma ṣe eyiti o tọ́ li
oju OLUWA Ọlọrun rẹ.

## ORI 14.

ỌMỌ OLUWA Ọlọrun nyin li ẹnyin iṣe:
ẹnyin kò gbọdọ̀ bù ara nyin li abẹ,
bẹ̃ni ẹnyin kò gbọdọ fá iwaju nyin nitori
okú.
2 Nitoripe enia mimọ́ ni iwọ́ fun OLUWA
Ọlọrun rẹ, OLUWA si ti yàn ọ lati ma ṣe
enia ọ̀tọ fun ara rẹ̀, jù gbogbo orilẹ-èdè lọ
ti mbẹ lori ilẹ.
3 Iwọ kò gbọdọ jẹ ohun irira kan.
4 Wọnyi li ẹranko ti ẹnyin o ma jẹ:
akọmalu, agutan, ati ewurẹ,
5 Agbọnrin, ati esuwo, ati gala, ati
ewurẹ igbẹ́, ati pigargi, ati ẹfọ̀n, ati ẹtu.
6 Ati gbogbo ẹranko ti o là bàta-ẹsẹ̀,
ti o si pinyà bàta-ẹsẹ̀ si meji, ti o si njẹ
apọjẹ ninu ẹranko, eyinì ni ki ẹnyin ki o
ma jẹ.
7 Ṣugbọn wọnyi ni ẹnyin kò gbọdọ jẹ
ninu awọn ti njẹ apọjẹ, tabi ninu awọn
ti o là bàta-ẹsẹ̀; bi ibakasiẹ, ati ehoro,
ati garà, nitoriti nwọn njẹ apọjẹ ṣugbọn
nwọn kò là bàta-ẹsẹ̀, alaimọ́ ni nwọn jasi
fun nyin:
8 Ati ẹlẹdẹ̀, nitoriti o là bàta-ẹsẹ̀ ṣugbọn
kò jẹ apọjẹ, alaimọ́ ni fun nyin: ẹnyin kò
gbọdọ jẹ ninu ẹran wọn, bẹ̃li ẹnyin kò
gbọdọ fọwọkàn okú wọn.
9 Wọnyi ni ki ẹnyin ki o ma jẹ ninu
gbogbo eyiti mbẹ ninu omi: gbogbo eyiti
o ní lẹbẹ ti o si ní ipẹ́ ni ki ẹnyin ki o
ma jẹ.
10 Ati ohunkohun ti kò ba ní lẹbẹ ti kò
si ní ipẹ́, ki ẹnyin ki o máṣe jẹ ẹ; alaimọ́ ni
fun nyin.
11 Gbogbo ẹiyẹ ti o mọ́ ni ki ẹnyin ki o
ma jẹ.

Digitized by Google

12 Ṣugbọn wọnyi li awọn ti ẹnyin kò
gbọdọ jẹ ninu wọn: idì, ati aṣa-idì, ati
idì-ẹja.
13 Ati glede, ati aṣá, ati gunugunu li
onirũru rẹ̀;
14 Ati gbogbo ìwo li onirũru rẹ̀;
15 Ati ogongo, ati owiwi, ati ẹlulu, ati
awodi li onirũru rẹ̀;
16 Owiwi kekere, ati owiwi nla, ati
ogbugbu;
17 Ati pelikan, ati àkala, ati ìgo;
18 Ati àkọ, ati ondẹ li onirũru rẹ̀, ati
atọka, ati adán.
19 Ati ohun gbogbo ti nrakò ti nfò, o
jẹ́ alaimọ́ fun nyin: a kò gbọdọ jẹ wọn.
20 Ṣugbọn gbogbo ẹiyẹ ti o mọ́ ni ki
ẹnyin ki o ma jẹ.
21 Ẹnyin kò gbọdọ jẹ ohunkohun ti o
tikara rẹ̀ kú: iwọ le fi i fun alejò ti mbẹ
ninu ibode rẹ, ki on ki o jẹ ẹ; tabi ki iwọ
ki o tà a fun ajeji: nitoripe enia mimọ́ ni
iwọ fun OLUWA Ọlọrun rẹ. Iwọ kò gbọdọ
bọ̀ ọmọ ewurẹ ninu warà iya rẹ̀.
22 Ki iwọ ki o dá idamẹwa gbogbo ibisi
irugbìn rẹ, ti nti oko rẹ wá li ọdọdún.
23 Niwaju OLUWA Ọlọrun rẹ, ni ibi ti
on o gbé yàn lati fi orukọ rẹ̀ si, ni ki iwọ
ki o si ma jẹ idamẹwa ọkà rẹ, ti ọti-waini
rẹ, ati ti oróro rẹ, ati akọ́bi ọwọ́-ẹran rẹ,
ati ti agbo-ẹran rẹ; ki iwọ ki o le ma kọ́
ati bẹ̀ru OLUWA Ọlọrun rẹ nigbagbogbo.
24 Bi ọ̀na na ba si jìn jù fun ọ, ti iwọ
ki yio fi le rù u lọ, tabi bi ibi ti OLUWA
Ọlọrun rẹ yio yàn lati fi orukọ rẹ̀ si ba jìn
jù fun ọ, nigbati OLUWA Ọlọrun rẹ ba
bukún ọ:
25 Njẹ ki iwọ ki o yi i si owo, ki iwọ ki
o si dì owo na li ọwọ́ rẹ, ki o si lọ si ibi na,
ti OLUWA Ọlọrun rẹ yio yàn.
26 Ki iwọ ki o si ná owo na si ohun-
kohun ti ọkàn rẹ ba fẹ́, si akọmalu, tabi
agutan, tabi ọti-waini, tabi ọti lile kan,
tabi si ohunkohun ti ọkàn rẹ ba fẹ́: ki iwọ
ki o si ma jẹ nibẹ̀ niwaju OLUWA Ọlọrun
rẹ, ki iwọ ki o si ma yọ̀, iwọ, ati awọn ara
ile rẹ:
27 Ati ọmọ Lefi ti mbẹ ninu ibode rẹ;
iwọ kò gbọdọ kọ̀ ọ silẹ; nitoriti kò ní ipín
tabi iní pẹlu rẹ.
28 Li opin ọdún mẹta ni ki iwọ ki o mú
gbogbo idamẹwa ibisi rẹ wa li ọdún na, ki
iwọ ki o si gbé e kalẹ ninu ibode rẹ:
29 Ati ọmọ Lefi, nitoriti kò ní ipín tabi
iní pẹlu rẹ, ati alejò, ati alainibaba, ati
opó, ti mbẹ ninu ibode rẹ, yio wá, nwọn o
si jẹ nwọn o si yó; ki OLUWA Ọlọrun rẹ
ki o le bukún ọ ninu gbogbo iṣẹ ọwọ́ rẹ ti
iwọ nṣe.

## ORI 15.

LẸHIN ọdún mejemeje ni ki iwọ ki o
ma ṣe ijọwọlọwọ.
2 Ọ̀na ijọwọlọwọ na si li eyi: gbogbo
onigbese ti o wín ẹnikeji rẹ̀ ni nkan ki o
jọwọ rẹ̀ lọwọ; ki o ma ṣe fi agbara bère rẹ̀
lọwọ ẹnikeji rẹ̀, tabi lọwọ arakọnrin rẹ̀;
nitoriti a pè e ni ijọwọlọwọ OLUWA.
3 Iwọ le fi agbara bère lọwọ alejò: ṣu-
gbọn eyiti ṣe tirẹ ti mbẹ li ọwọ́ arakọnrin
rẹ, ni ki iwọ ki o jọwọ rẹ̀ lọwọ.
4 Ṣugbọn ki yio sí talaka ninu nyin;
(nitoripe OLUWA yio busi i fun ọ pupọ̀ ni
ilẹ na, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ni iní
lati gbà a;)
5 Kìki bi iwọ ba fi ifarabalẹ fetisi ohùn
OLUWA Ọlọrun rẹ, lati ma kiyesi gbogbo
ofin yi, ti mo filelẹ li aṣẹ fun ọ li oni
lati ṣe.
6 Nitoripe OLUWA Ọlọrun rẹ yio busi i
fun ọ, bi o ti ṣe ileri fun ọ: iwọ o si ma
wín ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède, ṣugbọn iwọ ki yio
tọrọ; iwọ o si ma ṣe olori ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède,
ṣugbọn nwọn ki yio ṣe olori rẹ.
7 Bi talakà kan ba mbẹ ninu nyin, ọkan
ninu awọn arakọnrin rẹ, ninu ibode rẹ kan,
ni ilẹ rẹ ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ, ki
iwọ ki o máṣe mu àiya rẹ le si i, bẹ̃ni ki
iwọ ki o máṣe há ọwọ́ rẹ si talakà arakọnrin
rẹ:
8 Ṣugbọn lilà ni ki iwọ ki o là ọwọ́ rẹ
fun u, ki iwọ ki o si wín i li ọ̀pọlọpọ tó
fun ainí rẹ̀, li ohun ti nfẹ́.
9 Ma kiyesara ki ìro buburu kan ki o
máṣe sí ninu àiya rẹ, wipe, Ọdún keje,
ọdún ijọwọlọwọ sunmọtosi; oju rẹ a si
buru si arakọnrin rẹ talakà, ti iwọ kò si
fun u ni nkan; on a si kigbe pè OLUWA
nitori rẹ, a si di ẹ̀ṣẹ fun ọ.
10 Ki iwọ ki o fi fun u nitõtọ, ki inu rẹ
ki o máṣe bàjẹ́ nigbati iwọ ba fi fun u:
nitoripe nitori nkan yi ni OLUWA Ọlọrun
rẹ yio busi i fun ọ ni gbogbo iṣẹ rẹ, ati ni
gbogbo ohun ti iwọ ba fi ọwọ́ rẹ lé.
11 Nitoripe talakà kò le tán ni ilẹ na:
nitorina ni mo ṣe paṣẹ fun ọ, wipe, Ki iwọ
ki o là ọwọ́ rẹ fun arakọnrin rẹ, fun talakà
rẹ, ati fun alainí rẹ, ninu ilẹ rẹ.
12 Ati bi a ba tà arakọnrin rẹ kan fun ọ,
ọkọnrin Heberu, tabi obirin Heberu, ti o
si sìn ọ li ọdún mẹfa; njẹ li ọdún keje ki
iwọ ki o rán a lọ kuro lọdọ rẹ li omnira.
13 Nigbati iwọ ba si nrán a lọ li omnira

Digitized by Google

kuro lọdọ rẹ, iwọ kò gbọdọ jẹ ki o lọ li ọwọ́ ofo:

14 Ki iwọ ki o pèse fun u li ọ̀pọlọpọ lati inu agbo-ẹran rẹ wá, ati lati ilẹ-ipakà rẹ, ati lati ibi ifunti rẹ, ninu eyiti OLUWA Ọlọrun rẹ fi bukún ọ ni ki iwọ ki o fi fun u.

15 Ki iwọ ki o si ranti pe, iwọ a ti ma ṣe ẹrú ni ilẹ Egipti, ati pe OLUWA Ọlọrun rẹ si gbà ọ silẹ: nitorina ni mo ṣe fi aṣẹ nkan yi lelẹ fun ọ li oni.

16 Yio si ṣe, bi o ba wi fun ọ pe, Emi ki yio jade lọ kuro lọdọ rẹ; nitoriti o fẹ́ ọ ati ile rẹ, nitoriti o dara fun u lọdọ rẹ;

17 Nigbana ni ki iwọ ki o mú olu kan, ki iwọ ki o si fi lu u li etí mọ́ ara ilẹkun, ki on ki o si ma ṣe ọmọ-ọdọ rẹ lailai. Ati ọmọ-ọdọ rẹ obirin ni ki iwọ ki o ṣe bẽ si gẹgẹ.

18 Ki o máṣe ro ọ loju, nigbati iwọ ba rán a li omnira lọ kuro lọdọ rẹ; nitoriti o ní iye lori to alagbaṣe meji ni sìsin ti o sìn ọ li ọdún mẹfa: OLUWA Ọlọrun rẹ yio si busi i fun ọ ninu gbogbo ohun ti iwọ nṣe.

19 Gbogbo akọ́bi akọ ti o ti inu ọwọ-ẹran rẹ ati inu agbo-ẹran rẹ wá, ni ki iwọ ki o yàsi-mimọ́, fun OLUWA Ọlọrun rẹ: iwọ kò gbọdọ fi akọ́bi ninu akọmalu rẹ ṣe iṣẹ kan, bẽni iwọ kò gbọdọ rẹrun akọ́bi agutan rẹ.

20 Ki iwọ ki o ma jẹ ẹ niwaju OLUWA Ọlọrun rẹ li ọdọdún, ni ibi ti OLUWA yio yàn, iwọ, ati awọn ara ile rẹ.

21 Bi abùkun kan ba si wà lara rẹ̀, bi o mọkun ni, bi o fọju ni, tabi bi o ní abùkun buburu kan, ki iwọ ki o máṣe fi rubọ si OLUWA Ọlọrun rẹ.

22 Ki iwọ ki o jẹ ẹ ninu ibode rẹ: alaimọ́ ati ẹni ti o mọ́ ni ki o jẹ ẹ bakanna, bi esuwo, ati bi agbọnrin.

23 Kìki iwọ kò gbọdọ jẹ ẹ̀jẹ rẹ̀; ki iwọ ki o dà a silẹ bi omi.

## ORI 16.

IWỌ ma kiyesi oṣù Abibu, ki o si ma pa ajọ irekọja mọ́ si OLUWA Ọlọrun rẹ: nitoripe li oṣù Abibu ni OLUWA Ọlọrun rẹ mú ọ lati ilẹ Egipti jade wa li oru.

2 Nitorina ki iwọ ki o ma pa ẹran irekọja si OLUWA Ọlọrun rẹ, ninu agbo-ẹran ati ninu ọwọ́-ẹran, ni ibi ti OLUWA yio yàn lati fi orukọ rẹ̀ si.

3 Iwọ kò gbọdọ jẹ àkara wiwu pẹlu rẹ̀; ijọ́ meje ni iwọ o fi jẹ àkara alaiwu pẹlu rẹ̀, ani onjẹ ipọnju; nitoripe iwọ ti ilẹ Egipti jade wá ni kanjukanju: ki iwọ ki o le ma ranti ọjọ́, ti iwọ ti ilẹ Egipti jade wa, li ọjọ́ aiye rẹ gbogbo.

4 Ki a má si ṣe ri àkara wiwu lọdọ rẹ li àgbegbe rẹ gbogbo ni ijọ́ meje; bẽni ki ohun kan ninu ẹran ti iwọ o fi rubọ li ọjọ́ kini li aṣalẹ, ki o máṣe kù di owurọ̀.

5 Ki iwọ ki o máṣe pa ẹran irekọja na ninu ibode rẹ kan, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ:

6 Ṣugbọn bikoṣe ni ibi ti OLUWA Ọlọrun rẹ yio yàn lati fi orukọ rẹ̀ si, nibẹ̀ ni ki iwọ ki o pa ẹran irekọja na li aṣalẹ, nigba ìwọ-õrùn, li akokò ti iwọ ti ilẹ Egipti jade wá.

7 Ki iwọ ki o si sun u, ki iwọ ki o si jẹ ẹ ni ibi ti OLUWA Ọlọrun rẹ yio yàn: ki iwọ ki o si pada li owurọ̀, ki o si lọ sinu agọ́ rẹ.

8 Ijọ́ mẹfa ni iwọ o fi jẹ àkara alaiwu: ati ni ijọ́ keje ki ajọ kan ki o wà fun OLUWA Ọlọrun rẹ; ninu rẹ̀ iwọ kò gbọdọ ṣe iṣẹ kan.

9 Ọsẹ meje ni ki iwọ ki o kà fun ara rẹ: bẹ̀rẹsi ati kà ọ̀sẹ meje na lati ìgba ti iwọ ba tẹ̀ doje bọ̀ ọkà.

10 Ki iwọ ki o si pa ajọ ọ̀sẹ mọ́ si OLUWA Ọlọrun rẹ pẹlu ọrẹ ifẹ́-atinuwa ọwọ́ rẹ, ti iwọ o fi fun u, gẹgẹ bi OLUWA Ọlọrun rẹ ti busi fun ọ:

11 Ki iwọ ki o si ma yọ̀ niwaju OLUWA Ọlọrun rẹ, iwọ, ati ọmọ rẹ ọkọnrin, ati ọmọ rẹ obirin, ati ọmọ-ọdọ rẹ ọkọnrin, ati ọmọ-ọdọ rẹ obirin, ati ọmọ Lefi ti mbẹ ninu ibode rẹ, ati alejò, ati alainibaba, ati opó, ti mbẹ lãrin rẹ, ni ibi ti OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé yàn, lati fi orukọ rẹ̀ si.

12 Ki iwọ ki o si ma ranti pe, ẹrú ni iwọ ti jẹ́ ni Egipti: ki iwọ ki o si ma kiyesi ati ṣe ìlana wọnyi.

13 Ki iwọ ki o si ma pa ajọ agọ́ mọ́ li ọjọ́ meje, lẹhin ìgba ti iwọ ba ṣe ipalẹmọ ilẹ-ipakà rẹ ati ibi-ifunti rẹ.

14 Ki iwọ ki o si ma yọ̀ ninu ajọ rẹ, iwọ, ati ọmọ rẹ ọkọnrin, ati ọmọ rẹ obirin, ati ọmọ-ọdọ rẹ ọkọnrin, ati ọmọ-ọdọ rẹ obirin, ati ọmọ Lefi, ati alejò, ati alainibaba, ati opó, ti mbẹ ninu ibode rẹ.

15 Ijọ́ meje ni ki iwọ ki o fi ṣe ajọ si OLUWA Ọlọrun rẹ ni ibi ti OLUWA yio yàn: nitoriti OLUWA Ọlọrun rẹ yio busi i fun ọ ni gbogbo asunkún rẹ, ati ninu gbogbo iṣẹ ọwọ́ rẹ, nitorina ki iwọ ki o ma yọ̀ nitõtọ.

16 Lẹ̃mẹta li ọdún ni ki gbogbo awọn ọkọnrin rẹ ki o farahàn niwaju OLUWA Ọlọrun rẹ, ni ibi ti on o gbé yàn; ni ajọ àkara alaiwu, ati ni ajọ ọ̀sẹ, ati ni ajọ agọ́:

Digitized by Google

ki nwọn ki o má si ṣe ṣánwọ wá iwaju
OLUWA:
17 Ki olukuluku ki o mú ọrẹ wá bi
agbara rẹ̀ ti to, gẹgẹ bi ibukún OLUWA
Ọlọrun rẹ ti o fi fun ọ.
18 Awọn onidajọ ati awọn ijoye ni ki
iwọ ki o fi jẹ ninu ibode rẹ gbogbo, ti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ, gẹgẹ bi ẹ̀ya rẹ:
ki nwọn ki o si ma ṣe idajọ awọn enia na
li ododo.
19 Iwọ kò gbọdọ lọ́ idajọ; iwọ kò gbọdọ
ṣe ojusaju enia: bẽni iwọ kò gbọdọ gbà
ẹ̀bun; nitoripe ẹ̀bun ni ifọ́ ọlọgbọ́n li oju,
on a si yi ọ̀rọ olododo po.
20 Eyiti iṣe ododo patapata ni ki iwọ ki
o ma tọ̀ lẹhin, ki iwọ ki o le yè, ki iwọ
ki o si ní ilẹ na ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi
fun ọ.
21 Iwọ kò gbọdọ rì igi oriṣa kan sunmọ
pẹpẹ OLUWA Ọlọrun rẹ, ti iwọ o mọ fun
ara rẹ.
22 Bẽni iwọ kò gbọdọ gbé ọwọ̀n kan
kalẹ fun ara rẹ: ti OLUWA Ọlọrun rẹ
korira.

ORI 17.

IWỌ kò gbọdọ fi akọmalu, tabi agutan, ti
o lí àbukun, tabi ohun buburu kan
rubọ si OLUWA Ọlọrun rẹ: nitoripe irira ni
si OLUWA Ọlọrun rẹ.
2 Bi a ba ri lãrin nyin, ninu ibode rẹ
kan ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ, ọkọnrin
tabi obirin ti nṣe nkan buburu li oju OLUWA
Ọlọrun rẹ, ni rire majẹmu rẹ̀ kọja,
3 Ti o si lọ ti o nsin ọlọrun miran, ti o
si mbọ wọn, iba ṣe õrùn, tabi oṣupa, tabi
ọkan ninu ogun ọrun, ti emi kò palaṣẹ;
4 Ti a ba si wi fun ọ, ti iwọ si ti gbọ́, ti
iwọ si wádi rẹ̀ rere, si kiyesi i, ti o jasi
otitọ, ti ohun na si daniloju pe, a ṣe irú
irira yi ni Israeli;
5 Nigbanã ni ki iwọ ki o mú ọkọnrin
tabi obirin na, ti o ṣe ohun buburu yi jade
wá, si ibode rẹ, ani ọkọnrin tabi obirin na,
ki iwọ ki o si sọ wọn li okuta pa.
6 Li ẹnu ẹlẹri meji, tabi ẹlẹri mẹta, li a
o pa ẹniti o yẹ si ikú; ṣugbọn li ẹnu ẹlẹri
kan, a ki yio pa a.
7 Ọwọ́ awọn ẹlẹri ni yio tète wà lara
rẹ̀ lati pa a, lẹhin na ọwọ́ gbogbo enia.
Bẽni iwọ o si mú ìwabuburu kuro lãrin
nyin.
8 Bi ẹjọ́ kan ba ṣoro jù fun ọ lati dá,
lãrin ẹ̀jẹ on ẹ̀jẹ, lãrin ọ̀ran on ọ̀ran, ati
lãrin ìluni ati ìluni, ti iṣe ọ̀ran iyàn ninu
ibode rẹ, nigbana ni ki iwọ ki o dide, ki o
si gòke lọ si ibi ti OLUWA Ọlọrun rẹ yio
yàn;
9 Ki iwọ ki o si tọ̀ awọn alufa, awọn
ọmọ Lefi lọ, ati onidajọ ti yio wà li ọjọ́
wọnni: ki o si bère; nwọn o si fi ọ̀rọ idajọ
hàn ọ:
10 Ki iwọ ki o si ṣe bi ọ̀rọ idajọ, ti awọn
ará ibi ti OLUWA yio yàn na yio fi hàn ọ;
ki iwọ ki o si ma kiyesi ati ma ṣe gẹgẹ bi
gbogbo eyiti nwọn kọ́ ọ:
11 Gẹgẹ bi ọ̀rọ ofin ti nwọn o kọ́ ọ, ati
gẹgẹ bi idajọ ti nwọn o wi fun ọ, ni ki
iwọ ki o ṣe: ki iwọ ki o máṣe yà si ọwọ́
ọtún, tabi si òsi, kuro li ọ̀rọ ti nwọn o fi
hàn ọ.
12 Ọkọnrin na ti o ba si fi igberaga ṣe e,
ti kò fẹ́ gbọ́ ti alufa na, ti o duro lati ma
ṣe iṣẹ alufa nibẹ̀ niwaju OLUWA Ọlọrun rẹ,
tabi lati gbọ́ ti onidajọ na, ani ọkọnrin na
yio kú: iwọ o si mú ìwabuburu kuro ni
Israeli.
13 Gbogbo enia yio si gbọ́, nwọn o si
bẹru, nwọn ki yio si gberaga mọ́.
14 Nigbati iwọ ba dé ilẹ na ti OLUWA
Ọlọrun rẹ fi fun ọ, ti iwọ ba si gbà a, ti iwọ
ba si joko ninu rẹ̀, ti iwọ o si wipe, Emi o
fi ọba jẹ lori mi, gẹgẹ bi gbogbo awọn orilẹ-
ède ti o yi mi ká;
15 Kìki ẹniti OLUWA Ọlọrun rẹ yio yàn,
ni ki iwọ ki o fi jọba lori rẹ: ọkan ninu
awọn arakọnrin rẹ ni ki iwọ ki o fi jọba lori
rẹ: ki iwọ ki o máṣe fi alejò ṣe olori rẹ, ti
ki iṣe arakọnrin rẹ.
16 Ṣugbọn on kò gbọdọ kó ẹṣin jọ fun
ara rẹ̀, bẽni ki o máṣe mu awọn enia pada
lọ si Egipti, nitori ki o ba le kó ẹṣin jọ:
nitori OLUWA ti wi fun nyin pe, Ẹnyin kò
gbọdọ tun pada lọ li ọ̀na na mọ́.
17 Bẽni ki o máṣe kó obirin jọ fun ara
rẹ̀, ki àiya rẹ̀ ki o má ba yipada: bẽni ki
o máṣe kó fadakà tabi wurá jọ fun ara rẹ̀ li
ọ̀pọlọpọ.
18 Yio si ṣe, nigbati o ba joko lori itẹ́
ijọba rẹ̀, ki on ki o si kọ iwé ofin yi sinu
iwé kan fun ara rẹ̀, lati inu eyiti mbẹ ni-
waju awọn alufa awọn ọmọ Lefi:
19 Yio si wà lọdọ rẹ̀, on o si ma kà ninu
rẹ̀ li ọjọ́ aiye rẹ̀ gbogbo: ki o le ma kọ́ ati
bẹru OLUWA Ọlọrun rẹ̀, lati ma pa gbogbo
ọ̀rọ ofin yi mọ́ ati ilana wọnyi, lati ma ṣe
wọn:
20 Ki àiya rẹ̀ ki o má ba gbega jù awọn
arakọnrin rẹ̀ lọ, ati ki o má ba yipada kuro
ninu ofin na, si ọwọ́ ọtún, tabi si òsi: ki
on ki o le mu ọjọ́ rẹ̀ pẹ ni ijọba rẹ̀, on, ati
awọn ọmọ rẹ̀, lãrin Israeli.



Digitized by Google

## ORI 18.

AWỌN alufa, awọn ọmọ Lefi, ani gbogbo
ẹ̀ya Lefi, ki yio ní ipín tabi iní pẹlu
Israeli: ki nwọn ki o ma jẹ ẹbọ OLUWA
ti a fi iná ṣe, ati iní rẹ̀ ni ki nwọn bi o
ma jẹ.
2 Nitorina ni nwọn ki yio ṣe ni iní lãrin
awọn arakọnrin wọn: OLUWA ni iní wọn,
bi o ti wi fun wọn.
3 Eyi ni yio si ma jẹ́ ipín awọn alufa
lati ọdọ awọn enia wá, lati ọdọ awọn ti o
ru ẹbọ, iba ṣe akọmalu tabi agutan, ki
nwọn ki o si fi apa fun alufa, ati ẹrẹkẹ
mejeji ati àpo.
4 Akọ́so ọkà rẹ pẹlu, ati ti ọti-waini rẹ,
ati ti oróro rẹ, ati akọ́rẹ irun agutan rẹ, ni
ki iwọ ki o fi fun u.
5 Nitori OLUWA Ọlọrun rẹ li o yàn a
ninu gbogbo awọn ẹ̀ya rẹ, lati ma duro ṣe
iṣẹ-ìsin li orukọ OLUWA, on ati awọn ọmọ
rẹ̀ lailai.
6 Ati bi omọ Lefi kan ba ti inu ibode rẹ
kan wá, ni gbogbo Israeli, nibiti o gbé nṣe
atipo, ti o si fi gbogbo ifẹ́ inu rẹ̀ wá si ibi
ti OLUWA yio yàn;
7 Njẹ ki o ma ṣe iṣẹ-ìsin li orukọ OLUWA
Ọlọrun rẹ̀, bi gbogbo awọn arakọnrin rẹ̀
awọn ọmọ Lefi, ti nduro nibẹ̀ niwaju
OLUWA.
8 Ipín kanna ni ki nwọn ki o ma jẹ,
làika eyiti o ní nipa tità ogún baba rẹ̀.
9 Nigbati iwọ ba dé ilẹ na ti OLUWA
Ọlọrun rẹ fi fun ọ, ki iwọ ki o máṣe kọ́
ati ṣe gẹgẹ bi ìwa-irira awọn orilẹ-ède
wọnni.
10 Ki a máṣe ri ninu nyin ẹnikan ti nmu
ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, tabí ọmọ rẹ̀ obirin là iná
já, tabi nfọ̀ afọ̀ṣẹ, tabi alakiyesi-ìgba, tabi
aṣefàiya, tabi ajẹ́,
11 Tabi atuju, tabi aba-iwin-gbìmọ, tabi
oṣó, tabi abokulò.
12 Niroripe gbogbo awọn ti nṣe nkan
wọnyi irira ni si OLUWA: ati nitori irira
wọnyi ni OLUWA Ọlọrun rẹ ṣe lé wọn jade
kuro niwaju rẹ.
13 Ki iwọ ki o pé lọdọ OLUWA Ọlọrun
rẹ.
14 Nitori orilẹ-ède wọnyi ti iwọ o gbà,
nwọn fetisi awọn alakiyesi-ìgba, ati si awọn
alafọ̀ṣẹ: ṣugbọn bi o ṣe tirẹ ni, OLUWA
Ọlọrun rẹ kò gbà fun ọ bẽ.
15 OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé wolĩ kan
dide fun ọ lãrin rẹ, ninu awọn arakọnrin
rẹ, bi emi; on ni ki ẹnyin ki o fetisi;
16 Gẹgẹ bi gbogbo eyiti iwọ bère lọwọ
OLUWA Ọlọrun rẹ ni Horebu li ọjọ́ ajọ nì,
wipe, Máṣe jẹ ki emi tun gbọ́ ohùn OLUWA
Ọlọrun mi mọ́, bẽni ki emi ki o má tun ri
iná nla yi mọ́; ki emi ki o mà ba kú.
17 OLUWA si wi fun mi pe, Nwọn wi
rere li eyiti nwọn sọ.
18 Emi o gbé wolĩ kan dide fun wọn
lãrin awọn arakọnrin wọn, bi iwọ; emi o
si fi ọ̀rọ mi si i li ẹnu, on o si sọ fun wọn
gbogbo eyiti mo palaṣẹ.
19 Yio si ṣe, ẹniti kò ba fetisi ọ̀rọ mi
ti on o ma sọ li orukọ mi, emi o bère
lọwọ rẹ̀.
20 Ṣugbọn wolĩ na, ti o kùgbu sọ ọ̀rọ
kan li orukọ mi, ti emi kò fun u li aṣẹ lati
sọ, tabi ti o sọ̀rọ li orukọ ọlọrun miran, ani
wolĩ na yio kú.
21 Bi iwọ ba si wi li ọkàn rẹ pe, Bawo
li awa o ṣe mọ̀ ọ̀rọ ti OLUWA kò sọ?
22 Nigbati wolĩ kan ba sọ̀rọ li orukọ
OLUWA, bi ohun na kò ba ri bẽ, ti kò ba si
ṣẹ, eyinì li ohun ti OLUWA kò sọ: wolĩ na
li o fi ikùgbu sọ̀rọ: ki iwọ ki o máṣe bẹ̀ru
rẹ̀.

## ORI 19.

NIGBATI OLUWA Ọlọrun rẹ ba ke awọn
orilẹ-ède wọnni kuro, ilẹ ẹniti OLUWA
Ọlọrun rẹ fi fun ọ, ti iwọ si rọpò wọn, ti
iwọ si joko ni ilu wọn, ati ni ile wọn;
2 Ki iwọ ki o yà ilu mẹta sọ̀tọ fun ara rẹ
lãrin ilẹ rẹ, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ
lati ní.
3 Ki iwọ ki o là ọ̀na kan fun ara rẹ, ki
iwọ ki o si pín àgbegbe ilẹ rẹ si ipa mẹta,
ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ lati ní, ki
gbogbo apania ki o ma sá sibẹ̀.
4 Eyi si ni ọ̀ran apania, ti yio ma sá
sibẹ̀, ki o le yè: ẹnikẹni ti o ba ṣeṣi pa
ẹnikeji rẹ̀, ti on kò korira rẹ̀ tẹlẹrí;
5 Bi nigbati enia ba wọ̀ inu igbó lọ pẹlu
ẹnikeji rẹ̀ lati ke igi, ti o si fi ọwọ́ rẹ́ gbé
ãke lati fi ke igi na lulẹ, ti ãke si yọ kuro
ninu erú, ti o si bà ẹnikeji rẹ̀, ti on kú; ki
o salọ si ọkan ninu ilu wọnni, ki o si yè:
6 Ki agbẹsan ẹ̀jẹ ki o má ba lepa apania
na, nigbati ọkàn rẹ̀ gboná, ki o si lé e bá,
nitoriti ọ̀na na jín, a si pa a; nigbati o jẹ
pe kò yẹ lati kú, niwọnbi on kò ti korira
rẹ̀ tẹlẹrí.
7 Nitorina emi fi aṣẹ fun ọ wipe, Ki iwọ
ki o yà ilu mẹta sọtọ̀ fun ara rẹ.
8 Ati bi OLUWA Ọlọrun rẹ ba sọ àgbe-
gbe rẹ di nla, ti on ti bura fun awọn baba
rẹ, ti o sì fun ọ ni gbogbo ilẹ na, ti o si ṣe
ileri fun awọn baba rẹ;

Digitized by Google

9 Bi iwọ ba pa gbogbo ofin yi mọ́ lati
ma ṣe e, ti mo filelẹ li aṣẹ fun ọ li oni, lati
ma fẹ́ OLUWA Ọlọrun rẹ, ati lati ma rìn
titi li ọ̀na rẹ̀; nigbana ni ki iwọ ki o fi ilu
mẹta kún u si i fun ara rẹ, pẹlu mẹta
wọnyi;
10 Ki a má ba tà ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ silẹ ninu ilẹ
rẹ, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ni iní, ki
ẹ̀jẹ ki o má ba wà li ọrùn rẹ.
11 Ṣugbọn bi ọkọnrin kan ba korira
ẹnikeji rẹ̀, ti o si ba dè e, ti o si dide si i,
ti o si lù u li alupa, ti o si kú, ti on si salọ
sinu ọkan ninu ilu wọnyi:
12 Njẹ ki awọn àgba ilu rẹ̀ ki o ránni ki
nwọn ki o si mú u ti ibẹ̀ wá, ki nwọn ki o
si fà a lé agbẹsan ẹ̀jẹ lọwọ ki o ba le kú.
13 Ki oju rẹ ki o máṣe ṣãnu fun u,
ṣugbọn ki iwọ ki o mú ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ kuro lori
Israeli, ki o si le dara fun ọ.
14 Iwọ kò gbọdọ yẹ̀ àla ẹnikeji rẹ, ti
awọn ara iṣaju ti pa ni ilẹ iní rẹ ti iwọ o
ní, ni ilẹ na ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ
lati ní.
15 Ki ẹlẹri kanṣoṣo ki o máṣe dide jẹri
tì enia nitori aiṣedede kan, tabi nitori ẹ̀ṣẹ
kan ninu ẹ̀ṣẹ ti o ba ṣẹ̀: li ẹnu ẹlẹri meji,
tabi li ẹnu ẹlẹri mẹta, li ọ̀ran yio fẹṣẹmulẹ.
16 Bi ẹlẹri eké ba dide si ọkọnrin lati
jẹri tì i li ohun ti kò tọ́:
17 Njẹ ki awọn ọkọnrin mejeji na lãrin
ẹniti ọ̀rọ iyàn na gbé wà, ki o duro niwaju
OLUWA, niwaju awọn alufa ati awọn oni-
dajọ, ti yio wà li ọjọ wọnni,
18 Ki awọn onidajọ na ki o si tọ̀sẹ rẹ̀
pẹlẹpẹlẹ: si kiyesi i bi ẹlẹri na ba ṣe ẹlẹri
eké, ti o si jẹri-eké si arakọnrin rẹ̀;
19 Njẹ ki ẹnyin ki o ṣe si i, bi on ti rò
lati ṣe si arakọnrin rẹ̀: bẹ̃ni iwọ o si mú
ìwabuburu kuro lãrin nyin.
20 Awọn ti o kù yio si gbọ́, nwọn o si
bẹ̀ru, nwọn ki o si tun hù irú ìwabuburu
bẹ̃ mọ́ lãrin nyin.
21 Ki oju rẹ ki o má si ṣe ṣãnu; ẹmi
fun ẹmi, oju fun oju, ehín fun ehín, ọwọ́,
fun ọwọ́, ẹsẹ̀ fun ẹsẹ̀.

## ORI 20.

NIGBATI iwọ ba jade ogun si awọn ọtá
rẹ, ti iwọ si ri ẹṣin, ati kẹkẹ́-ogun, ati
awọn enia ti o pọ̀ jù ọ, máṣe bẹ̀ru wọn:
nitori OLUWA Ọlọrun rẹ wà pẹlu rẹ, ti o
mú ọ lati ilẹ Egipti jade wá.
2 Yio si ṣe, nigbati ẹnyin ba sunmọ
ogun na, ki alufa ki o sunmọtosi, ki o si
sọ̀rọ fun awọn enia.
3 Ki o si wi fun wọn pe, Gbọ́, Israeli, li
oni ẹnyin sunmọ ogun si awọn ọtá nyin:
ẹ máṣe jẹ ki àiya nyin ki o ṣojo, ẹ máṣe
bẹ̀ru, ẹ má si ṣe warìri, bẹ̃ni ẹ má si ṣe fòya
nitori wọn;
4 Nitoripe OLUWA Ọlọrun nyin ni mbá
nyin lọ, lati bá awọn ọtá nyin jà fun nyin,
lati gbà nyin là.
5 Ki awọn olori-ogun ki o si sọ fun
awọn enia, pe, Ọkọnrin wo li o kọ ile
titun, ti kò ti ikó si i? jẹ ki o pada lọ si
ile rẹ̀, ki on ki o mà ba kú li ogun na, ki
ọkọnrin miran ki o má ba kó si i.
6 Ati ọkọnrin wo li o gbìn ọgbà-àjara, ti
kò si ti ijẹ ninu rẹ̀? jẹ ki on pẹlu ki o
pada lọ si ile rẹ̀, ki on ki o má ba kú li
ogun na, ki ọkọnrin miran ki o má ba
jẹ ẹ.
7 Ati ọkọnrin wo li o fẹ́ iyawo, ti kò ti
igbé e? jẹ ki o pada lọ si ile rẹ̀, ki on ki o
má ba kú li ogun na, ki ọkọnrin miran ki
o má ba gbé e.
8 Ki awọn olori-ogun ki o si sọ fun awọn
enia na si i, ki nwọn ki o si wipe, Ọkọnrin
wo li o wà ti o bẹ̀ru ti o si nṣojo? jẹ ki o
pada lọ si ile rẹ̀, ki àiya awọn arakọnrin rẹ̀
ki o má ba ṣojo pẹlu bi àiya tirẹ̀.
9 Yio si ṣe, nigbati awọn olori-ogun ba
pari ọ̀rọ sisọ fun awọn enia tán, ki nwọn
ki o si fi awọn balogun jẹ́ lori awọn enia na.
10 Nigbati iwọ ba sunmọ ilu kan lati
bá a jà, nigbana ni ki iwọ ki o fi alafia
lọ̀ ọ.
11 Yio si ṣe, bi o ba da ọ lohùn alafia,
ti o si ṣilẹkun silẹ fun ọ, njẹ yio ṣe, gbo-
gbo awọn enia ti a ba bá ninu rẹ̀, nwọn o
si ma jẹ́ ọlọsin fun ọ, nwọn o si ma sìn ọ.
12 Bi kò ba si fẹ́ bá ọ ṣe alafia, ṣugbọn
bi o ba fẹ́ bá ọ jà, njẹ ki iwọ ki o dótì i:
13 Nigbati OLUWA Ọlọrun rẹ ba fi i lé ọ
lọwọ, ki iwọ ki o si fi oju idà pa gbogbo
ọkọnrin ti mbẹ ninu rẹ̀:
14 Ṣugbọn awọn obirin, ati awọn ọmọ
wẹ́wẹ ati ohunọ̀sin, ati ohun gbogbo ti mbẹ̀
ni ilu na, ani gbogbo ikogun rẹ̀, ni ki iwọ
ki o kó fun ara rẹ; ki iwọ ki o si ma jẹ
ikogun awọn ọtá rẹ, ti OLUWA Ọlọrun rẹ
fi fun ọ.
15 Bayi ni ki iwọ ki o ṣe si gbogbo ilu
ti o jìna rére si ọ, ti ki iṣe ninu ilu awọn
orilẹ-ède wọnyi.
16 Ṣugbọn ninu ilu awọn enia wọnyi, ti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ni iní, ki iwọ ki
o máṣe da ohun kan si ti o nmí:
17 Ṣugbọn ki iwọ ki o pa wọn run pata-
pata; awọn ọmọ Hitti, ati awọn Amori,
awọn ara Kenaani, ati awọn Perissi, awọn

Digitized by Google

Hifi, ati awọn Jebusi; bi OLUWA Ọlọrun
rẹ ti paṣẹ fun ọ:
18 Ki nwọn ki o má ba kọ́ nyin lati ma
ṣe bi gbogbo iṣẹ-irira wọn, ti nwọn ti nṣe
si awọn oriṣa wọn; ẹnyin a si ṣẹ̀ bẽ si
OLUWA Ọlọrun nyin.
19 Nigbati iwọ ba dótì ilu kan pẹ titi,
lati bá a jà lati kó o, ki iwọ ki o máṣe run
igi tutù rẹ̀ ni yiyọ ãke tì wọn; nitoripe
iwọ le ma jẹ ninu won, iwọ kò si gbọdọ ke
wọn lulẹ; nitori igi igbẹ́ ha ṣe enia bi, ti
iwọ o ma dótí i?
20 Kìki igi ti iwọ mọ̀ pe nwọn ki iṣe igi
jijẹ, on ni ki iwọ ki o run, ki o si ke lulẹ;
ki iwọ ki o si sọ agbàra tì ilu na ti mbá ọ
jà, titi a o fi ṣẹ́ ẹ.

## ORI 21.

BI a ba ri ẹnikan ti a pa ni ilẹ na ti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ lati gbà a,
ti o dubulẹ ni igbẹ́, ti a kò si mọ̀ ẹniti o
pa a:
2 Nigbana ni ki awọn àgba rẹ ati awọn
onidajọ rẹ ki o jade wá, ki nwọn ki o si
wọn jijìna awọn ilu ti o yi ẹniti a pa na ká.
3 Yio si ṣe, pe ilu ti o sunmọ ẹniti a pa
na, ani awọn àgba ilu na ki nwọn mú
ẹgbọrọ abomalu kan, ti a kò fi ṣiṣẹ rí, ti
kò si fà ninu àjaga rí;
4 Ki awọn àgba ilu na ki o mú ẹgbọrọ
abomalu na sọkalẹ wá, si afonifoji ti o ní
omi ṣiṣàn kan, ti a kò ro ti a kò si gbìn,
ki nwọn ki o si ṣẹ́ ọrùn ẹgbọrọ abomalu na
nibẹ̀ li afonifoji na:
5 Awọn alufa, awọn ọmọ Lefi yio si
sunmọtosi; nitoripe awọn ni OLUWA Ọlọ-
run rẹ yàn lati ma ṣe iṣẹ-ìsin fun u, ati lati
ma sure li orukọ OLUWA; nipa ọ̀rọ wọn li
a o ti ma wadi ọ̀ran iyàn ati ọ̀ran lilù:
6 Ati gbogbo awọn àgba ilu nì, ti o
sunmọ ẹniti a pa na, ki nwọn ki o wẹ̀ ọwọ́
wọn sori ẹgbọrọ abomalu na, ti a ṣẹ́ li ọrùn
li afonifoji nì:
7 Ki nwọn ki o si dahùn wipe, Ọwọ́ wa
kò tà ẹ̀jẹ yi silẹ, bẽli oju wa kò ri i.
8 OLUWA, darijì Israeli awọn enia rẹ,
ti iwọ ti ràpada, ki o má si ṣe kà ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀
si ọrùn Israeli awọn enia rẹ. A o si dari
ẹ̀jẹ na jì wọn.
9 Bẽni iwọ o si mú ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ kuro lãrin
nyin, nigbati iwọ ba nṣe eyiti o tọ́ li oju
OLUWA.
10 Nigbati iwọ ba jade ogun si awọn ọtá
rẹ, ti OLUWA Ọlọrun rẹ si fi wọn lé ọ lọwọ,
ti iwọ si dì wọn ni igbekun;
11 Ti iwọ ba si ri ninu awọn igbẹsin na
arẹwà obirin, ti iwọ si ní ifẹ́ si i, pe ki iwọ
ki o ní i li aya rẹ;
12 Nigbana ni ki iwọ ki o mú u wá sinu
ile rẹ; ki on ki o si fá ori rẹ̀, ki o si rẹ́
ẽkanna rẹ̀;
13 Ki o si bọ́ aṣọ igbẹsin rẹ̀ kuro lara rẹ̀,
ki o si joko ninu ile rẹ, ki o sọkun baba
rẹ̀, ati iya rẹ̀ li oṣù kan tọtọ: lẹhin ìgba
na ki iwọ ki o wọle tọ̀ ọ, ki o si ma ṣe ọkọ
rẹ̀, on a si ma ṣe aya rẹ.
14 Bi o ba si ṣe, ti on kò ba wù ọ, njẹ
ki iwọ ki o jẹ ki o ma lọ si ibi ti o fẹ́;
ṣugbọn iwọ kò gbọdọ tà a rára li owo, iwọ
kò gbọdọ lò o bi ẹrú, nitoriti iwọ ti té ẹ
logo.
15 Bi ọkọnrin kan ba si lí aya meji, ti
o fẹ́ ọkan, ti o si korira ekeji, ti nwọn si bi
ọmọ fun u, ati eyiti o fẹ́ ati eyiti o korira;
bi akọ́bi ọmọ na ba ṣe ti ẹniti o korira;
16 Yio si ṣe, li ọjọ́ ti o ba fi awọn ọmọ
rẹ̀ jogún ohun ti o ní, ki o máṣe fi ọmọ
obirin ti o fẹ́ ṣe akọ́bi ni ipò ọmọ obirin ti
o korira, ti iṣe akọ́bi:
17 Ṣugbọn ki o jẹwọ ọmọ obirin ti o
korira li akọ́bi, ni fifi ipín meji fun u ninu
ohun gbogbo ti o ní: nitoripe on ni ipilẹṣẹ
agbara rẹ̀; itọsi akọ́bi ni tirẹ̀.
18 Bi ọkọnrin kan ba lí ọmọkọnrin kan
tí o ṣe agídi ati alaigbọran, ti kò gbà ohùn
baba rẹ̀ gbọ́, tabi ohùn iya rẹ̀, ati ti nwọn
nà a, ti kò si fẹ́ gbà ti wọn gbọ́:
19 Nigbana ni ki baba rẹ̀ ati iya rẹ̀ ki o
mú u, ki nwọn ki o si fà a jade tọ̀ awọn
àgba ilu rẹ̀ wá ati si ibode ibujoko rẹ̀;
20 Ki nwọn ki o si wi fun awọn àgba
ilu rẹ̀ pe, Ọmọ wa yi, agídi ati alaigbọran
ni, on kò fẹ́ gbọ́ ohùn wa; ọjẹun ati ọmọti
ni.
21 Ki gbogbo awọn ọkọnrin ilu rẹ̀ ki o
sọ ọ li okuta pa: bẽni ki iwọ ki o mú ìwà-
ibi kuro lãrin nyin: gbogbo Israeli a si
gbọ́, nwọn a si bẹ̀ru.
22 Bi ọkọnrin kan ba dá ẹ̀ṣẹ kan ti o yẹ
si ikú, ti a si pa a, ti iwọ si so o lori igi;
23 Ki okú rẹ̀ ki o máṣe gbé ori igi ni
gbogbo oru, ṣugbọn bi o ti wù ki o ṣe ki
iwọ ki o sin i li ọjọ́ na; nitoripe ẹni egún
Ọlọrun li ẹniti a so; ki iwọ ki o má ba bà
ilẹ rẹ jẹ́, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ni
iní.

## ORI 22.

IWỌ kò gbọdọ ri akọmalu tabi agutan
arakọnrin rẹ ti o nṣako, ki iwọ ki o si
mú oju rẹ kuro lara wọn; bi o ti wù ki o

Digitized by Google

ṣe ki iwọ ki o mú wọn pada tọ̀ arakọnrin
rẹ wá.
2 Bi arakọnrin rẹ kò ba si sí nitosi rẹ,
tabi bi iwọ kò ba mọ̀ ọ, njẹ ki iwọ ki o mú
u wá sinu ile rẹ, ki o si wà lọdọ rẹ titi
arakọnrin rẹ yio fi wá a wá, ki iwọ ki o si
fun u pada.
3 Bẽ na ni ki iwọ ki o ṣe si kẹtẹkẹtẹ rẹ̀;
bẽ na ni ki iwọ ki o ṣe si aṣọ rẹ̀; bẽ na ni
ki iwọ ki o si ṣe si gbogbo ohun ninù
arakọnrin rẹ, ti o nù lọwọ rẹ̀, ti iwọ si ri:
ki iwọ ki o máṣe mú oju rẹ kuro.
4 Iwọ kò gbọdọ ri kẹtẹkẹtẹ tabi akọ-
malu arakọnrin rẹ ki o ṣubu li ọ̀na, ki iwọ
ki o si mú oju rẹ kuro lara wọn: iwọ o si
ràn a lọwọ nitõtọ lati gbé e dide.
5 Obirin kò gbọdọ mú ohun ti iṣe ti
ọkọnrin wọ̀, bẽli ọkọnrin kò gbọdọ mú aṣọ
obirin wọ̀; nitoripe gbogbo ẹniti o ba ṣe bẽ
irira ni nwọn si Oluwa Ọlọrun rẹ.
6 Bi iwọ ba bá itẹ́ ẹiyẹ kan pade lori igi
kan, tabi ni ilẹ, ti o ní ọmọ tabi ẹyin, ti
iya si bà lé ọmọ tabi lé ẹyin na, iwọ kò
gbọdọ kó iya pẹlu ọmọ:
7 Bikoṣe ki iwọ ki o jọwọ iya lọwọ lọ,
ki iwọ ki o si kó ọmọ fun ara rẹ; ki o le
dara fun ọ, ati ki iwọ ki o le mu ọjọ́ rẹ pẹ.
8 Nigbati iwọ ba kọ ile titun kan, ki
iwọ ki o ṣe igbáti si orule rẹ, ki iwọ o má
ba mú ẹ̀jẹ wá sara ile rẹ, bi ẹnikan ba ti
ibẹ̀ ṣubu.
9 Iwọ kò gbọdọ fi irú meji irugbìn gbìn
ọgbà-àjara rẹ: ki eso irugbìn rẹ gbogbo ti
iwọ ti gbìn, ati asunkún ọgbà-àjara rẹ, ki
o má ba di ti Ọlọrun.
10 Iwọ kò gbọdọ fi akọmalu ati kẹtẹ-
kẹtẹ tulẹ pọ̀.
11 Iwọ kò gbọdọ wọ̀ aṣọ olori-ori, ti
kubusu ati ti ọ̀gbọ pọ̀.
12 Ki iwọ ki o ṣe wajawaja si igun mẹ-
rẹrin aṣọ rẹ, ti iwọ fi mbò ara rẹ.
13 Bi ọkọnrin kan ba gbé iyawo kan, ti
o wọle tọ̀ ọ, ti o si korira rẹ̀,
14 Ti o si kà ọ̀ran si i lọrùn, ti o si bà
orukọ rẹ̀ jẹ́, ti o si wipe, Mo gbé obirin yi,
nigbati mo si wọle tọ̀ ọ, emi kò bá a ni
wundia:
15 Nigbana ni ki baba ọmọbirin na, ati
iya rẹ̀, ki o mú àmi wundia ọmọbirin na
tọ̀ awọn àgba ilu lọ li ẹnubode:
16 Ki baba ọmọbirin na ki o si wi fun
awọn àgba na pe, Emi fi ọmọbirin mi fun
ọkọnrin yi li aya, o si korira rẹ̀;
17 Si kiyesi i, o si kà ọ̀ran si i lọrùn,
wipe, Emi kò bá ọmọbirin rẹ ni wundia;
bẽni wọnyi ni àmi wundia ọmọbirin mi. Ki
nwọn ki o si nà aṣọ na niwaju awọn àgba
ilu.
18 Ki awọn àgba ilu na ki o si mú ọkọn-
rin na ki nwọn ki o si nà a;
19 Ki nwọn ki o si bù ọgọrun ṣekeli
fadakà fun u, ki nwọn ki o si fi i fun baba
ọmọbirin na, nitoriti o bà orukọ wundia
kan ni Israeli jẹ́: ki on ki o si ma ṣe aya
rẹ̀; ki o máṣe kọ̀ ọ li ọjọ́ aiye rẹ̀ gbogbo.
20 Ṣugbọn bi ohun na ba ṣe otitọ, ti a
kò ba si ri àmi wundia ọmọbirin na:
21 Nigbana ni ki nwọn ki o mú ọmọbi-
rin na wá si ẹnu-ọ̀na ile baba rẹ̀, ki awọn
ọkọnrin ilu rẹ̀ ki o sọ ọ li okuta pa: nito-
riti o hù ìwabuburu ni Israeli, ni ṣiṣe àgbe-
re ninu ile baba rẹ̀: bẽni ki iwọ ki o mú
ìwabuburu kuro lãrin nyin.
22 Bi a ba mú ọkọnrin kan ti o bá obirin
kan dàpọ, ti a gbé ni iyawo fun ọkọ, njẹ
ki awọn mejeji ki o kú, ati ọkọnrin ti o bá
obirin na dàpọ, ati obirin na: bẽni ki iwọ
ki o si mú ìwabuburu kuro ni Israeli.
23 Bi ọmọbirin wundia kan ba wà ti
afẹsọna fun ọkọ, ti ọkọnrin kan si ri i ni
ilu, ti o si bá a dàpọ;
24 Njẹ ki ẹnyin ki o mú awọn mejeji wá
si ẹnubode ilu na, ki ẹnyin ki o si sọ wọn
li okuta pa; eyi ọmọbirin nitoriti kò kigbe,
nigbati o wà ni ilu; ati eyi ọkọnrin nito-
riti o tẹ́ aya ẹnikeji rẹ̀ logo: bẽni ki iwọ
ki o mú ìwabuburu kuro lãrin nyin.
25 Ṣugbọn bi ọkọnrin na ba ri ọmọbirin
ti afẹsọna na ni igbẹ́, ti ọkọnrin na si fi
agbara mú u, ti o si bà a dàpọ; njẹ kìki
ọkọnrin na ti o bá a dàpọ ni ki o kú:
26 Ṣugbọn si ọmọbirin na ni ki iwọ ki o
máṣe ohun kan; ẹ̀ṣẹ ti o yẹ si ikú kò sí
lara ọmọbirin na: nitori bi igbati ọkọnrin
kan dide si ẹnikeji rẹ̀, ti o si pa a, bẽli ọ̀ran
yi ri:
27 Nitoripe o bá a ninu igbẹ́; ọmọbirin
na ti afẹsọna kigbe, kò si sí ẹniti yio gbà a
silẹ.
28 Bi ọkọnrin kan ba si ri ọmọbirin kan
ti iṣe wundia, ti a kò ti fẹsọna fun ọkọ, ti
o si mú u, ti o si bá a dàpọ, ti a si mú
wọn;
29 Njẹ ki ọkọnrin na ti o bá a dàpọ ki o
fi ãdọta ṣekeli fadakà fun baba ọmọbirin
na, ki on ki o si ma ṣe aya rẹ̀, nitoriti o ti
tẹ́ ẹ logo, ki on ki o máṣe kọ̀ ọ silẹ li ọjọ́
aiye rẹ̀ gbogbo.
30 Ki ọkọnrin kan ki o máṣe fẹ́ aya baba
rẹ̀, bẽni ki o máṣe tú aṣọ baba rẹ̀.

Digitized by Google

## ORI 23.

ENITI a fọ ni kóro, tabi ti a ke ẹ̀ya ìkọkọ
rẹ̀ kuro, ki yio wọ̀ inu ijọ enia
OLUWA.
2 Ọmọ àle ki yio wọ̀ inu ijọ enia OLUWA;
ani dé iran kẹwa enia rẹ̀ kan ki yio wọ̀ inu
ijọ enia OLUWA.
3 Ọmọ Ammoni tabi ọmọ Moabu kan ki
yio wọ̀ inu ijọ enia OLUWA; ani dé iran
kẹwa enia wọn kan ki yio wọ̀ inu ijọ enia
OLUWA lailai:
4 Nitoriti nwọn kò fi omi pẹlu onjẹ pade
nyin li ọ̀na, nigbati ẹnyin nti Egipti jade
wá; ati nitoriti nwọn bẹ̀wẹ Balaamu ọmọ
Beori ara Petori ti Mesopotamia si ọ, lati
fi ọ bú.
5 Ṣugbọn OLUWA Ọlọrun rẹ kò fẹ́ fetisi
ti Balaamu; OLUWA Ọlọrun rẹ si yi egún
na pada si ibukún fun ọ, nitoriti OLUWA
Ọlọrun rẹ fẹ́ ọ.
6 Iwọ kò gbọdọ wá alafia wọn tabi ire
wọn li ọjọ́ rẹ gbogbo lailai.
7 Iwọ kò gbọdọ korira ara Edomu kan;
nitoripe arakọnrin rẹ ni iṣe: iwọ kò gbọdọ
korira ara Egipti kan; nitoripe iwọ ti ṣe
alejò ni ilẹ rẹ̀.
8 Awọn ọmọ ti a bi fun wọn yio wọ̀ inu
ijọ enia OLUWA ni iran kẹta wọn.
9 Nigbati iwọ ba jade ogun si awọn ọtá
rẹ, nigbana ni ki iwọ ki o pa ara rẹ mọ́ kuro
ninu ohun buburu gbogbo.
10 Bi ọkọnrin kan ba wà ninu nyin, ti
o ṣèşi di aimọ́ li oru, njẹ ki o jade lọ sẹhin
ibudó, ki o máṣe wá ãrin ibudó:
11 Yio si ṣe, nigbati alẹ ba lẹ, ki on ki
o fi omi wẹ̀ ara rẹ̀: nigbati õrùn ba si wọ̀,
ki o ma bọwá sãrin ibudó.
12 Ki iwọ ki o ní ibi kan pẹlu lẹhin
ibudó, nibiti iwọ o ma jade lọ si:
13 Ki iwọ ki o si ní ìwalẹ kan pẹlu
ohun-ìja rẹ; yio si ṣe, nigbati iwọ o ba
gbọnsẹ lẹhin ibudó, ki iwọ ki o fi wàlẹ, ki
iwọ ki o si yipada, ki o bò ohun ti o ti ara
rẹ jade:
14 Nitoripe OLUWA Ọlọrun rẹ nrìn lãrin
ibudó rẹ, lati gbà ọ, ati lati fi awọn ọtá rẹ
fun ọ; nitorina ki ibudó rẹ ki o jẹ́ mimọ́:
ki on ki o máṣe ri ohun aimọ́ kan lọdọ rẹ,
on a si pada lẹhin rẹ.
15 Iwọ kò gbọdọ fà ẹrú ti o sá lati ọdọ
oluwa rẹ̀ tọ̀ ọ wá lé oluwa rẹ̀ lọwọ:
16 Ki on ki o bá ọ joko, ani lãrin nyin,
ni ibi ti on o yàn ninu ọkan ni ibode rẹ, ti
o wù u jù: ki iwọ ki o máṣe ni i lara.
17 Ki àgbere ki o máṣe sí ninu awọn
ọmọbirin Israeli, tabi onìwa-sodomu ninu
awọn ọmọkọnrin Israeli.
18 Iwọ kò gbọdọ mú owo ọ̀ya àgbere,
tabi owo ajá, wá sinu ile OLUWA Ọlọrun rẹ
fun ẹjẹ́kẹjẹ: nitoripe irira ni, ani awọn meji
si OLUWA Ọlọrun rẹ.
19 Iwọ kò gbọdọ wín arakọnrin rẹ fun
elé; elé owo, elé onjẹ, elé ohun kan ti a
wínni li elé:
20 Alejò ni ki iwọ ki o ma wín fun elé;
ṣugbọn arakọnrin rẹ ni ki iwọ ki o máṣe
wín fun elé: ki OLUWA Ọlọrun rẹ ki o le
ma bukún ọ ninu ohun gbogbo ti iwọ ba fi
ọwọ́ rẹ lé, ni ilẹ na nibiti iwọ nlọ lati gbà
a.
21 Nigbati iwọ ba jẹ́jẹ kan fun OLUWA
Ọlọrun rẹ, ki iwọ ki o máṣe fàsẹhin lati san
a: nitoripe OLUWA Ọlọrun rẹ yio bère rẹ̀
nitõtọ lọwọ rẹ; yio si di ẹ̀ṣẹ si ọ lọrùn.
22 Ṣugbọn bi iwọ ba fàsẹhin lati jẹ́jẹ, ki
yio di ẹ̀ṣẹ si ọ lọrùn.
23 Ohun ti o ba ti ète rẹ jade, ni ki iwọ
ki o pamọ́, ki o si ṣe; gẹgẹ bi iwọ ti jẹ́jẹ
fun OLUWA Ọlọrun rẹ, ani ọrẹ ifẹ́-atinuwa,
ti iwọ ti fi ẹnu rẹ ṣe ileri.
24 Nigbati iwọ ba wọ̀ inu ọgbà-àjara
ẹnikeji rẹ lọ, iwọ le jẹ eso-àjara tẹrùn;
ṣugbọn iwọ kò gbọdọ mú ọkan sinu ohun-
èlo rẹ.
25 Nigbati iwọ ba dé inu oko-ọkà ẹnikeji
rẹ, njẹ ki iwọ ki o ma fi ọwọ́ rẹ yà ṣiri rẹ̀;
ṣugbọn iwọ kò gbọdọ yọ doje si ọkà ẹnikeji
rẹ.

## ORI 24.

BI ọkọnrin kan ba fẹ́ obirin kan, ti o si
gbé e niyawo, yio si ṣe, bi obirin na
kò ba ri ojurere li oju ọkọnrin na, nitoriti
o ri ohun alebù kan lara rẹ̀; njẹ ki o kọ
iwé ikọsilẹ fun obirin na, ki o fi i lé e lọwọ,
ki o si rán a jade kuro ninu ile rẹ̀.
2 Nigbati on ba si jade kuro ninu ile rẹ̀,
on le lọ, ki o ma ṣe aya ọkọnrin miran.
3 Bi ọkọ rẹ̀ ikẹhin ba si korira rẹ̀, ti o si
kọ iwé ikọsilẹ fun u, ti o si fi i lé e lọwọ,
ti o si rán a jade kuro ninu ile rẹ̀; tabi bi
ọkọ ikẹhin ti o fẹ́ ẹ li aya ba kú;
4 Ọkọ rẹ̀ iṣaju, ti o rán a jade kuro, ki
o máṣe tun ní i li aya lẹhin ìgba ti o ti di
ẹni-ibàjẹ́ tán; nitoripe irira ni niwaju
OLUWA: iwọ kò si gbọdọ mu ilẹ na ṣẹ̀, ti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ni iní.
5 Bi ọkọnrin kan ba gbé iyawo titun, ki
o máṣe lọ si ogun, bẹ̃ni ki a máṣe fun u ni
iṣẹkiṣẹ kan ṣe: ki o ri àye ni ile li ọdún
kan, ki o le ma mu inu aya rẹ̀ ti o ní dùn.

Digitized by Google

6 Ẹnikan kò gbọdọ gbà iya-ọlọ tabi ọmọ-
ọlọ ni ògo : nitoripe ẹmi enia li o gbà li
ògo nì.
7 Bi a ba mú ọkọnrin kan ti njí ẹnikan
ninu awọn arakọnrin rẹ̀, awọn ọmọ Israeli,
ti o nsìn i bi ẹrú, tabi ti o tà a ; njẹ olè na
o kú ; bẹ̃ni iwọ o mú ìwabuburu kuro làrin
nyin.
8 Ma kiyesi àrun-ẹ̀tẹ, ki iwọ ki o ṣọra
gidigidi ki o si ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti
awọn alufa awọn ọmọ Lefi yio ma kọ́ nyin:
bi emi ti pa a laṣẹ fun wọn, bẹ̃ni ki ẹnyin
ki o ma kiyesi lati ṣe.
9 Ranti ohun ti OLUWA Ọlọrun rẹ ṣe si
Miriamu li ọ̀na, nigbati ẹnyin ti Egipti
jade wá.
10 Nigbati iwọ ba wín arakọnrin rẹ li
ohun kan, ki iwọ ki o máṣe lọ si ile rẹ̀ lati
mú ògo rẹ̀ wá.
11 Ki iwọ ki o duro lode gbangba, ki
ọkọnrin na ti iwọ wín ni nkan, ki o mú
ògo rẹ̀ jade tọ̀ ọ wá.
12 Bi ọkọnrin na ba si ṣe talakà, ki iwọ
ki o máṣe sùn ti iwọ ti ògo rẹ̀.
13 Bi o ti wù ki o ri iwọ kò gbọdọ má
mú ògo rẹ̀ pada fun u, nigbati õrùn ba nwọ̀,
ki on ki o le ri aṣọ bora sùn, ki o si sure
fun ọ : ododo ni yio si jasi fun ọ niwaju
OLUWA Ọlọrun rẹ.
14 Iwọ kò gbọdọ ni alagbaṣe kan lara
ti iṣe talakà ati alaini, ibaṣe ninu awọn
arakọnrin rẹ, tabi ninu awọn alejò rẹ ti
mbẹ ni ilẹ rẹ ninu ibode rẹ :
15 Ni ọjọ́ rẹ̀, ni ki iwọ ki o sanwo ọ̀ya
rẹ̀ fun u, bẹ̃ni ki o máṣe jẹ ki õrùn ki o
wọ̀ bá a ; nitoripe talakà li on, o si gbẹkẹ
rẹ̀ lé e : ki o má ba kepè OLUWA si ọ, a si
di ẹ̀ṣẹ si ọ lọrùn.
16 A kò gbọdọ pa awọn baba nitori ẹ̀ṣẹ
awọn ọmọ, bẹ̃ni a kò gbọdọ pa awọn ọmọ
nitori awọn baba : olukuluku enia li a o
pa nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
17 Iwọ kò gbọdọ yi idajọ alejò po, tabi
ti alainibaba ; bẹ̃ni ki iwọ ki o máṣe gbà
aṣọ opó ni ògo :
18 Ṣugbọn ki iwọ ki o ranti pe iwọ ti ṣe
ẹrú ni Egipti, OLUWA Ọlọrun rẹ si gbà ọ
silẹ kuro nibẹ̀ : nitorina ni mo ṣe paṣẹ fun
ọ lati mã ṣe nkan yi.
19 Nigbati iwọ ba kore rẹ li oko rẹ, ti
iwọ ba si gbagbé ití-ọkà kan silẹ ninu oko,
ki iwọ ki o máṣe pada lọ mú u : ki o le ma
jẹ́ ti alejò, ti alainibaba, ati ti opó : ki
OLUWA Ọlọrun rẹ ki o le ma busi i fun ọ,
ninu iṣẹ ọwọ́ rẹ gbogbo.
20 Nigbati iwọ ba ngún igi olifi rẹ, ki
iwọ ki o máṣe tun pada wò ẹka rẹ̀ : ki eyinì
ki o jẹ́ ti alejò, ti alainibaba, ati ti opó.
21 Nigbati iwọ ba nká eso ọgbà-àjara rẹ,
ki iwọ ki o máṣe pẹṣẹ́ lẹhin rẹ : ki eyinì
ki o jẹ́ ti alejò, ti alainibaba, ati ti opó.
22 Ki iwọ ki o si ma ranti pe iwọ ti ṣe
ẹrú ni ilẹ Egipti : nitorina ni mo ṣe paṣẹ
fun ọ lati ma ṣe nkan yi.

## ORI 25.

BI gbolohùn-asọ̀ kan ba wà lãrin enia, ti
nwọn si wá si ibi idajọ, ti nwọn si dajọ
wọn ; nigbana ni ki nwọn ki o fi are fun
alare, ki nwọn ki o si fi ẹbi fun ẹlẹbi ;
2 Yio si ṣe, bi ẹlẹbi na ba yẹ lati nà, ki
onidajọ na ki o da a dọbalẹ, ki o si mu ki
a nà a ni iye kan li oju on, gẹgẹ bi ìwa-
buburu rẹ̀
3 Ogoji paṣan ni ki a nà a, kò gbọdọ lé :
nitoripe bi o ba lé, ti o ba si fi paṣan pupọ̀
nà a jù wọnyi lọ, njẹ arakọnrin rẹ yio di
gigàn li oju rẹ.
4 Máṣe di akọmalu li ẹnu nigbati o ba
npakà.
5 Bi awọn arakọnrin ba ngbé pọ̀, ti ọkan
ninu wọn ba si kú, ti kò si lí ọmọkọnrin,
ki aya okú ki o máṣe ní alejò ara ode li
ọkọ : arakọnrin ọkọ rẹ ni ki o wọle tọ̀ ọ, ki
o si ní i li aya, ki o si ṣe iṣẹ arakọnrin ọkọ
fun u.
6 Yio si ṣe, akọ́bi ọmọ ti o bi ki o rọpò
li orukọ arakọnrin rẹ̀ ti o kú, ki orukọ rẹ̀
ki o má ba parẹ́ ni Israeli.
7 Bi ọkọnrin na kò ba si fẹ́ lati mú aya
arakọnrin rẹ̀, njẹ ki aya arakọnrin rẹ̀ ki o
gòke lọ si ẹnubode tọ̀ awọn àgba lọ, ki o
si wipe, Arakọnrin ọkọ mi kọ̀ lati gbé
orukọ arakọnrin rẹ̀ ró ni Israeli, on kò fẹ́
ṣe iṣẹ arakọnrin ọkọ mi.
8 Nigbana ni awọn àgba ilu rẹ̀ yio pè e,
nwọn a si sọ fun u : bi o ba si duro si i, ti
o si wipe, Emi kò fẹ́ lati mu u ;
9 Nigbana ni aya arakọnrin rẹ̀ yio tọ̀ ọ
wa niwaju awọn àgba na, on a si tú bàta
rẹ̀ kuro li ẹsẹ̀ rẹ̀, a si tutọ si i li oju ; a si
dahùn, a si wipe, Bayi ni ki a ma ṣe si
ọkọnrin na ti kò fẹ́ ró ile arakọnrin rẹ̀.
10 A o si ma pè orukọ rẹ̀ ni Israeli pe,
Ile ẹniti a tú bàta rẹ̀.
11 Bi awọn ọkọnrin ba mbá ara wọn jà,
ti aya ọkan ba si sunmọtosi lati gbà ọkọ
rẹ̀ lọwọ ẹniti o kọlù u, ti on si nawọ́ rẹ̀, ti
o si di i mú li abẹ :
12 Nigbana ni ki iwọ ki o ke ọwọ́ rẹ̀
kuro, ki oju rẹ ki o máṣe ṣãnu fun u.

Digitized by Google

13 Iwọ kò gbọdọ ní onirũru ìwọn ninu
àpo rẹ, nla ati kekere.
14 Iwọ kò gbọdọ ní onirũru òṣuwọn ninu
ile rẹ, nla ati kekere.
15 Iwọn pipé ati dẽde ni ki iwọ ki o ní;
òṣuwọn pipé ati dẽde ni ki iwọ ki o ní: ki
ọjọ́ rẹ ki o le pẹ ni ilẹ ti OLUWA Ọlọrun rẹ
fi fun ọ.
16 Nitoripe gbogbo ẹniti nṣe wọnyi, ati
gbogbo ẹniti nṣe aiṣododo, irira ni si
OLUWA Ọlọrun rẹ.
17 Ranti ohun ti Amaleki ṣe si ọ li ọ̀na,
nígbati ẹnyin nti ilẹ Egipti jade wá;
18 Bi o ti pade rẹ li ọ̀na, ti o si kọlù
awọn ti o kẹhin rẹ, ani gbogbo awọn ti o
ṣe alailera lẹhin rẹ, nigbati ãrẹ mú ọ tán,
ti agara si dá ọ; ti on kò si bẹ̀ru Ọlọrun.
19 Nitorina yio si ṣe, nigbati OLUWA
Ọlọrun rẹ ba fun ọ ni isimi lọwọ gbogbo
awọn ọtá rẹ yi ọ ká kiri, ni ilẹ na ti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ni iní lati ní i,
ki iwọ ki o si pa iranti Amaleki rẹ́ kuro
labẹ ọrun; iwọ kò gbọdọ gbagbé.

## ORI 26.

YIO si ṣe, nigbati iwọ ba dé ilẹ na ti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ni iní, ti
iwọ si gbà a, ti iwọ si joko ninu rẹ̀;
2 Ki iwọ ki o mú ninu akọ́so gbogbo eso
ilẹ rẹ, ti iwọ o mú ti inu ilẹ rẹ wá, ti OLU-
WA Ọlọrun rẹ fi fun ọ; ki iwọ ki o si fi i
sinu agbọ̀n, ki iwọ ki o si lọ si ibi ti
OLUWA Ọlọrun rẹ yio yàn lati fi orukọ
rẹ̀ si.
3 Ki iwọ ki o si tọ̀ alufa na lọ ti yio wà
li ọjọ́ wọnni, ki o si wi fun u pe, Emi jẹwọ
li oni fun OLUWA Ọlọrun rẹ, pe emi wá si
ilẹ na ti OLUWA bura fun awọn baba wa
lati fi fun wa.
4 Ki awọn alufa ki o si gbà agbọ̀n na li
ọwọ́ rẹ, ki o si gbé e kalẹ niwaju pẹpẹ
OLUWA Ọlọrun rẹ.
5 Iwọ o si dahùn iwọ o si wi niwaju
OLUWA Ọlọrun rẹ pe, Ara Siria kan, ti o
nṣegbé ni baba mi, on si sọkalẹ lọ si Egipti,
o si ṣe atipo nibẹ̀, ti on ti enia diẹ; nibẹ̀
li o si di orilẹ-ède nla, alagbara, ati pupọ̀:
6 Awọn ara Egipti si hùwabuburu si wa,
nwọn si pọn wa loju, nwọn si dì ẹrù wuwo
rù wa:
7 Awa si kepè OLUWA, Ọlọrun awọn
baba wa, OLUWA si gbọ́ ohùn wa, o si wò
ipọnju wa, ati lãlã wa, ati inira wa:
8 OLUWA si mú wa lati Egipti jade wá
pẹlu ọwọ́ agbara, ati apa ninà, ati pẹlu ẹrù
nla, ati pẹlu iṣẹ-àmi, ati pẹlu iṣẹ-iyanu:
9 O si mú wa dé ihin yi, o si fi ilẹ yi
fun wa, ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin.
10 Njẹ nisisiyi, kiyesi i, emi mú akọ́so
ilẹ na wa, ti iwọ, OLUWA, fi fun mi. Ki
iwọ ki o si gbé e kalẹ niwaju OLUWA Ọlọ-
run rẹ, ki iwọ ki o si ma foribalẹ niwaju
OLUWA Ọlọrun rẹ:
11 Ki iwọ ki o si ma yọ̀ ninu ohun rere
gbogbo, ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ, ati
fun ara ile rẹ, iwọ, ati ọmọ Lefi, ati alejò
ti mbẹ lãrin rẹ.
12 Nigbati iwọ ba da idamẹwa asunkun
rẹ tán li ọdún kẹta, ti iṣe ọdún idamẹwa,
ti iwọ si fi fun ọmọ Lefi, alejò, alainibaba,
ati opó, ki nwọn ki o ma jẹ li ẹnubode rẹ,
ki nwọn si yó;
13 Nigbana ni ki iwọ ki o wi niwaju
OLUWA Ọlọrun rẹ pe, Emi ti mú ohun
mimọ́ kuro ninu ile mi, mo si ti fi wọn fun
ọmọ Lefi, ati fun alejò, ati fun alainibaba,
ati fun opó, gẹgẹ bi gbogbo aṣẹ rẹ ti iwọ ti
pa fun mi: emi kò re aṣẹ rẹ kọja, bẹ̃li emi
kò gbagbé wọn:
14 Emi kò jẹ ninu rẹ̀ ninu ọ̀fọ mi, bẹ̃li
emi kò mú kuro ninu rẹ̀ fun ohun aimọ́
kan, bẹ̃li emi kò mú ninu rẹ̀ fun okú:
ṣugbọn emi ti gbà ohùn OLUWA Ọlọrun mi
gbọ́, emi si ti ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti iwọ
palaṣẹ fun mi.
15 Wò ilẹ lati ibujoko mimọ́ rẹ wá, lati
ọrun wá, ki o si busi i fun Israeli enia rẹ,
ati fun ilẹ na ti iwọ fi fun wa, bi iwọ ti
bura fun awọn baba wa, ilẹ ti nṣàn fun
warà ati fun oyin.
16 Li oni OLUWA Ọlọrun rẹ paṣẹ fun ọ
lati ma ṣe ìlana ati idajọ wọnyi: nitorina
ki iwọ ki o ma pa wọn mọ́, ki iwọ ki o si
ma fi gbogbo àiya rẹ ati gbogbo ọkàn rẹ ṣe
wọn.
17 Iwọ jẹwọ OLUWA li oni pe on ni
Ọlọrun rẹ, ati pe iwọ o ma rìn li ọ̀na rẹ̀,
iwọ o si ma pa ìlana rẹ̀ mọ́, ati aṣẹ rẹ̀, ati
idajọ rẹ̀, iwọ o si ma fetisi ohùn rẹ̀:
18 OLUWA si jẹwọ rẹ li oni pe iwọ o ma
jẹ́ enia ọ̀tọ fun ara rẹ̀, bi on ti ṣe ileri fun
ọ, ati pe iwọ o ma pa gbogbo aṣẹ rẹ̀ mọ́;
19 On o si mu ọ ga jù orilẹ-ède gbogbo
lọ ti o dá, ni iyìn, li orukọ, ati ọlá; ki iwọ
ki o le ma jẹ́ enia mimọ́ fun OLUWA Ọlọrun
rẹ, bi o ti sọ.

## ORI 27.

MOSE pẹlu awọn àgba Israeli si paṣẹ fun
awọn enia na wipe, Ẹ ma pa gbogbo
ofin mọ́ ti mo filelẹ li aṣẹ fun nyin li oni.

Digitized by Google

2 Yio si ṣe li ọjọ́ ti ẹnyin ba gòke Jorda-
ni lọ si ilẹ ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ, ki
iwọ ki o si kó okuta nla jọ, ki iwọ ki o si
fi ẹfun rẹ́ wọ̀n.
3 Ki iwọ ki o si kọ gbogbo ọ̀rọ ofin yi
sara wọn, nigbati iwọ ba rekọja ; ki iwọ ki
o le wọ̀ inu ilẹ na lọ ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi
fun ọ, ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin, bi
OLUWA, Ọlọrun awọn baba rẹ, ti ṣe ileri
fun ọ.
4 Yio si ṣe, nigbati ẹnyin ba gòke Jorda-
ni tán, ẹnyin o kó okuta wọnyi jọ, ti mo
palaṣẹ fun nyin li oni li òke Ebali, ki iwọ
ki o si fi ẹfun rẹ́ wọn.
5 Nibẹ̀ ni ki iwọ ki o si mọ pẹpẹ kan fun
OLUWA Ọlọrun rẹ, pẹpẹ okuta kan: iwọ
kò gbọdọ fi ohun-èlo irin kàn wọn.
6 Okuta aigbẹ́ ni ki iwọ ki o fi mọ pẹpẹ
OLUWA Ọlọrun rẹ: ki iwọ ki o si ma ru
ẹbọ sisun lori rẹ̀ si OLUWA Ọlọrun rẹ:
7 Ki iwọ ki o si ma ru ẹbọ alafia, ki iwọ
ki o si jẹun nibẹ̀ ; ki iwọ ki o ma yọ̀ niwa-
ju OLUWA Ọlọrun rẹ.
8 Ki iwọ ki o si kọ gbogbo ọ̀rọ ofin yi
sara okuta wọnyi, ki o hàn gbangba.
9 Mose ati awọn alufa awọn ọmọ Lefi si
sọ fun gbogbo Israeli pe, Israeli, dakẹ, ki
o si gbọ́ ; li oni ni iwọ di ẹni OLUWA Ọlọ-
run rẹ.
10 Nitorina ki iwọ ki o gbà ohùn OLUWA
Ọlọrun rẹ gbọ́, ki o si ma ṣe aṣẹ rẹ̀ ati ìlana
rẹ̀, ti mo palaṣẹ fun ọ li oni.
11 Mose si paṣẹ fun awọn enia na li ọjọ́
na, wipe,
12 Awọn wọnyi ni ki o duro lori òke
Gerisimu, lati ma sure fun awọn enia na,
nigbati ẹnyin ba gòke Jordani ; Simeoni,
ati Lefi, ati Juda, ati Issakari, ati Josefu,
ati Benjamini:
13 Awọn wọnyi ni yio si duro lori òke
Ebali lati gégun ; Reubeni, Gadi, ati Aṣeri,
ati Sebuluni, Dani, ati Naftali.
14 Awọn ọmọ Lefi yio si dahùn, nwọn
o si wi fun gbogbo awọn ọkọnrin Israeli li
ohùn rara pe,
15 Egún ni fun ọkọnrin na ti o yá ere
gbigbẹ́ tabi didà, irira si OLUWA, iṣẹ ọwọ́
oniṣọnà, ti o si gbé e kalẹ ni ìkọkọ. Gbo-
gbo enia yio si dahùn wipe, Amin.
16 Egún ni fun ẹniti kò fi baba rẹ̀ tabi
iya rẹ̀ pè. Gbogbo enia yio si wipe,
Amin.
17 Egún ni fun ẹniti o ṣí àla ẹnikeji rẹ̀
kuro. Gbogbo enia yio si wipe, Amin.
18 Egún ni fun ẹniti o ṣì afọju li ọ̀na.
Gbogbo enia yio si wipe, Amin.
19 Egún ni fun ẹniti o nyi idajọ alejò
po, ati ti alainibaba, ati ti opó. Gbogbo
enia yio si wipe, Amin.
20 Egún ni fun ẹniti o bá aya baba rẹ̀
dàpọ: nitoriti o tú aṣọ baba rẹ̀. Gbogbo
enia yio si wipe, Amin.
21 Egún ni fun ẹniti o bá ẹranko dàpọ.
Gbogbo enia yio si wipe, Amin.
22 Egún ni fun ẹniti o bá arabirin rẹ̀
dàpọ, ti iṣe ọmọbirin baba rẹ̀, tabi ọmọbi-
rin iya rẹ̀. Gbogbo enia yio si wipe, Amin.
23 Egún ni fun ẹniti o bá iya-aya rẹ dà-
pọ. Gbogbo enia yio si wipe, Amin.
24 Egún ni fun ẹniti o lù ẹnikeji rẹ̀ ni
ìkọkọ. Gbogbo enia ni yio si wipe, Amin,
25 Egún ni fun ẹniti o gbà ọrẹ lati pa
alaiṣẹ̀. Gbogbo enia yio si wipe, Amin.
26 Egún ni fun ẹniti kò duro si gbogbo
ọ̀rọ ofin yi lati ṣe wọn. Gbogbo enia yio si
wipe, Amin.

## ORI 28.

YIO si ṣe, bi iwọ ba farabalẹ gbọ́ ohùn
OLUWA Ọlọrun rẹ, lati ma kiyesi ati
ṣe aṣẹ rẹ̀ gbogbo ti mo pa fun ọ li oni, njẹ
OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé ọ ga jù gbogbo
orilẹ-ède aiye lọ:
2 Gbogbo ibukún wọnyi yio si ṣẹ sori rẹ,
yio si bá ọ, bi iwọ ba fetisi ohùn OLUWA
Ọlọrun rẹ.
3 Ibukún ni fun ọ ni ilu, ibukún ni fun
ọ li oko.
4 Ibukún ni fun ọmọ inu rẹ, ati ẹso ilẹ
rẹ, ati irú ohunọ̀sin rẹ, ati ibisi malu rẹ,
ati ọmọ agutan rẹ.
5 Ibukún ni fun agbọ̀n rẹ ati fun ọpọ́n
ipò-àkara rẹ.
6 Ibukún ni fun ọ nigbati iwọ ba wọle,
ibukún ni fun ọ nigbati iwọ ba jade.
7 OLUWA yio mu awọn ọtá rẹ ti o dide
si ọ di ẹni ikọlù niwaju rẹ: nwọn o jade si
ọ li ọ̀na kan, nwọn o si sá niwaju rẹ li ọ̀na
meje.
8 OLUWA yio paṣẹ ibukún sori rẹ ninu
aká rẹ, ati ninu ohun gbogbo ti iwọ ba fi
ọwọ́ rẹ lé; on o si busi i fun ọ ni ilẹ na ti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ.
9 OLUWA yio fi idi rẹ kalẹ li enia mimọ́
fun ara rẹ̀, bi o ti bura fun ọ, bi iwọ ba pa
aṣẹ OLUWA Ọlọrun rẹ mọ́, ti iwọ si rìn li
ọ̀na rẹ̀.
10 Gbogbo enia aiye yio si ri pe orukọ
OLUWA li a fi npè ọ; nwọn o si ma bẹ̀ru
rẹ.
11 OLUWA yio si sọ ọ di pupọ̀ fun rere,

Digitized by Google

ninu ọmọ inu rẹ, ati ninu irú ohunọ̀sin rẹ, ati ninu eso ilẹ rẹ, ni ilẹ ti OLUWA ti bura fun awọn baba rẹ lati fun ọ.

12 OLUWA yio ṣí iṣura rere rẹ̀ silẹ fun ọ, ọrun lati rọ̀jo si ilẹ rẹ li akokò rẹ̀, ati lati busi iṣẹ ọwọ́ rẹ gbogbo: iwọ o si ma wín orilẹ-ède pupọ̀, iwọ ki yio si tọrọ.

13 OLUWA yio si fi ọ ṣe ori, ki yio si ṣe ìru; iwọ o si ma leke ṣá, iwọ ki yio si jẹ́ ẹni ẹhin; bi o ba fetisi aṣẹ OLUWA Ọlọrun rẹ, ti mo pa fun ọ li oni, lati ma kiyesi on ati ma ṣe wọn;

14 Iwọ kò si gbọdọ yà kuro ninu gbogbo ọ̀rọ ti mo palaṣẹ fun nyin li oni, si ọtún, tabi si òsi, lati tọ̀ ọlọrun miran lẹhin lati sìn wọn.

15 Yio si ṣe, bi iwọ kò ba fetisi ohùn OLUWA Ọlọrun rẹ, lati ma kiyesi ati ṣe gbogbo aṣẹ rẹ̀ ati ìlana rẹ̀ ti mo filelẹ fun ọ li oni; njẹ gbogbo egún wọnyi yio ṣẹ sori rẹ, yio si bá ọ.

16 Egún ni fun ọ ni ilu, egún ni fun ọ li oko.

17 Egún ni fun agbọ̀n rẹ ati ọpọ́n-ipòàkara rẹ.

18 Egún ni fun ọmọ inu rẹ, ati eso ilẹ rẹ, ibisi malu rẹ, ati ọmọ agutan rẹ.

19 Egún ni fun ọ nigbati iwọ ba wọle, egún si ni fun ọ nigbati iwọ ba jade.

20 OLUWA yio si rán egún, idamu, ati ibawi sori rẹ, ninu gbogbo ohun ti iwọ ba fi ọwọ́ rẹ lé ni ṣiṣe, titi a o fi run ọ, ati titi iwọ o fi ṣegbé kánkán; nitori buburu iṣe rẹ, nipa eyiti iwọ fi kọ̀ mi silẹ.

21 OLUWA yio si mu ajakalẹ-àrun lẹ̀ mọ́ ọ, titi on o fi run ọ kuro lori ilẹ na, nibiti iwọ nlọ lati gbà a.

22 OLUWA yio si fi àrun-igbẹ kọlù ọ, ati ibà, ati igbona, ati ijoni nla, ati idà, ati ìrẹdanu, ati imuwodu; nwọn o si lepa rẹ titi iwọ o fi run.

23 Ọrun rẹ ti mbẹ lori rẹ yio jẹ́ idẹ, ilẹ ti mbẹ nisalẹ rẹ yio si jẹ́ irin.

24 OLUWA yio sọ ọ̀jo ilẹ rẹ di busũ ati ekuru: lati ọrun ni yio ti ma sọkalẹ si ọ, titi iwọ o fi run.

25 OLUWA yio si mu ọ di ẹni ikọlù niwaju awọn ọtá rẹ: iwọ o jade tọ̀ wọn lọ li ọ̀na kan, iwọ o si sá niwaju wọn li ọ̀na meje: a o si ṣí ọ kiri gbogbo ijọba aiye.

26 Okú rẹ yio si jẹ́ onjẹ fun gbogbo ẹiyẹ ojuọrun, ati fun ẹranko aiye, kò si sí ẹniti yio lé wọn kuro.

27 OLUWA yio si fi õwo Egipti lù ọ, ati iyọdi, ati ekúru, ati ẹyi-ara, eyiti a ki yio le wòsan.

28 OLUWA yio fi isinwin kọlù ọ, ati ifọju, ati ipàiya:

29 Iwọ o si ma fi ọwọ́ talẹ li ọsán gangan, bi afọju ti ifi ọwọ́ talẹ ninu òkunkun, iwọ ki yio si ri rere ninu ọ̀na rẹ: ẹni inilara ṣá ati ẹni kikó li ọjọ́ gbogbo ni iwọ o jẹ́, kì o si sí ẹniti o gbà ọ.

30 Iwọ o fẹ́ iyawo, ọkọnrin miran ni yio si bá a dàpọ: iwọ o kọ ile, iwọ ki yio si gbé inu rẹ̀; iwọ o gbìn ọgbà-àjara, iwọ ki yio si ká eso rẹ̀.

31 A o si pa akọmalu rẹ li oju rẹ, iwọ ki yio si jẹ ninu rẹ̀: kẹtẹkẹtẹ rẹ li a o si fi agbara mú lọ kuro li oju rẹ, a ki yio si mú u pada fun ọ wá: a o fi agutan rẹ fun awọn ọtá rẹ, iwọ ki yio si lí ẹniti yio gbà ọ.

32 Awọn ọmọ rẹ ọkọnrin, ati awọn ọmọ rẹ obirin, li a o fi fun enia miran, oju rẹ yio ma wò, yio si su ọ lati ma wò ọ̀na wọn li ọjọ́ gbogbo; ki yio si sí agbara kan li ọwọ́ rẹ.

33 Eso ilẹ rẹ, ati gbogbo iṣẹ-lãlã rẹ, ni orilẹ-ède miran ti iwọ kò mọ̀ yio jẹ; iwọ o si jẹ́ kiki ẹni inilara ati ẹni itẹmọlẹ nigbagbogbo:

34 Bẹ̃ni iwọ o si di aṣiwere nitori iran oju rẹ, ti iwọ o ri.

35 OLUWA yio si fi õwo buburu lù ọ li ẽkún, ati li ẹsẹ̀, ti a ki o le wòsan, lati atẹlẹsẹ̀ rẹ dé atari rẹ.

36 OLUWA o mú iwọ, ati ọba rẹ ti iwọ o fi jẹ lori rẹ, lọ si orilẹ-ède ti iwọ, ati awọn baba rẹ kò mọ̀ rí; iwọ o si ma bọ oriṣa nibẹ̀, igi ati okuta.

37 Iwọ o si di ẹni iyanu, ati ẹni owe, ati ẹni ifiṣọrọsọ, ninu gbogbo orilẹ-ède, nibiti OLUWA yio gbé darí rẹ si.

38 Iwọ o mú irugbìn pupọ̀ lọ sinu oko, diẹ ni iwọ o si ri kójọ; nitoripe eṣú ni yio jẹ ẹ run.

39 Iwọ o gbìn ọgbà-àjara, iwọ o si ṣe itọju rẹ̀, ṣugbọn iwọ ki yio mu ninu ọti-waini rẹ̀, bẹ̃ni iwọ ki yio ká ninu eso-àjara rẹ̀, nitoripe kòkoro ni yio fi wọn jẹ.

40 Iwọ o ní igi olifi ni gbogbo àgbegbe rẹ, ṣugbọn iwọ ki yio fi oróro para; nitoripe igi olifi rẹ yio rẹ̀danu.

41 Iwọ o bi ọmọkọnrin ati ọmọbirin ṣugbọn nwọn ki yio jẹ́ tirẹ; nitoripe nwọn o lọ si oko-ẹrú.

42 Gbogbo igi rẹ ati eso ilẹ rẹ yio jẹ́ ti eṣú.

43 Alejò ti mbẹ lãrin rẹ, yio ma ga jù ọ lọ siwaju ati siwaju, iwọ o si ma di ẹni irẹsilẹ, siwaju ati siwaju.

44 On ni yio ma wín ọ, iwọ ki yio si

Digitized by Google

wín i : on ni yio ma ṣe ori, iwọ o si ma
ṣe ìru.
45 Gbogbo egún wọnyi yio si wá sori rẹ,
yio si lepa rẹ, yio si bá ọ, titi iwọ o fi run;
nitoriti iwọ kò fetisi ohùn OLUWA Ọlọrun
rẹ, lati pa aṣẹ rẹ̀ ati ìlana rẹ̀ mọ́ ti o palaṣe
fun ọ.
46 Nwọn o si wà lori rẹ fun àmi ati fun
iyanu, ati lori irú-ọmọ rẹ lailai :
47 Nitoriti iwọ kò fi àyọ sìn OLUWA
Ọlọrun rẹ, ati inudidun, nitori ọ̀pọ ohun
gbogbo :
48 Nitorina ni iwọ o ṣe ma sìn awọn ọtá
rẹ ti OLUWA yio rán si ọ́, ninu ebi, ati ninu
ongbẹ́, ati ninu ìhoho, ati ninu ainí ohun
gbogbo : on o si fi àjaga irin bọ̀ ọ li ọrùn,
titi yio fi run ọ.
49 OLUWA yio gbé orilẹ-ède kan dide si
ọ lati ọ̀na jijìn, lati opin ilẹ wa bi idì ti
ifò ; orilẹ-ède ti iwọ ki yio gbọ́ ède rẹ̀ ;
50 Orilẹ-ède ọdaju, ti ki yio ṣe ojusaju
arugbo, ti ki yio si ṣe ojurere fun ewe :
51 On o si ma jẹ irú ohunọ̀sin rẹ, ati eso
ilẹ rẹ, titi iwọ o fi run : ti ki yio kù ọkà,
ọti-waini, tabi oróro, tabi ibisi malu rẹ,
tabi ọmọ agutan silẹ fun ọ, titi on o fi
run ọ.
52 On o si dótì ọ ni ibode rẹ gbogbo,
titi odi rẹ ti o ga ti o si le yio fi wó lulẹ,
eyiti iwọ gbẹkẹle, ni ilẹ rẹ gbogbo : on o si
dótì ọ ni ibode rẹ gbogbo, ni gbogbo ilẹ rẹ,
ti OLUWA Ọlọrun rẹ ti fi fun ọ.
53 Iwọ o si jẹ ọmọ inu rẹ, ẹran ara awọn
ọmọ rẹ ọkọnrin ati ti awọn ọmọ rẹ obirin ti
OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ ; ninu idótì na
ati ninu ihámọ na ti awọn ọtá rẹ yio há ọ
mọ́.
54 Ọkọnrin ti àwọ rẹ̀ tutù ninu nyin, ti
o si ṣe ẹlẹgẹ, oju rẹ̀ yio korò si arakọnrin
rẹ̀, ati si aya õkanàiya rẹ̀, ati si iyokù ọmọ
rẹ̀ ti on jẹ kù :
55 Tobẽ ti on ki yio bùn ẹnikan ninu
wọn, ninu ẹran awọn ọmọ ara rẹ̀ ti o jẹ,
nitoriti kò sí ohun kan ti yio kù silẹ fun u
ninu idótì na ati ninu ihámọ, ti awọn ọtá
rẹ yio há ọ mọ́ ni ibode rẹ gbogbo.
56 Obirin ti awọ rẹ̀ tutù ninu nyin, ti o
si ṣe ẹlẹgẹ, ti kò jẹ daṣa ati fi atẹlẹsẹ̀ rẹ̀ kan
ilẹ nitori ikẹra ati ìwa-ẹlẹgẹ, oju rẹ̀ yio
korò si ọkọ õkanaiya rẹ̀, ati si ọmọ rẹ̀
ọkọnrin, ati ọmọ rẹ̀ obirin ;
57 Ati si ọmọ-ọwọ rẹ̀ ti o ti agbedemeji
ẹsẹ̀ rẹ̀ jade, ati si awọn ọmọ rẹ̀ ti yio bi ;
nitoripe on o jẹ wọn ni ìkọkọ nitori ainí
ohunkohun : ninu idótì ati ihámọ na, ti
ọtá rẹ yio há ọ mọ́ ni ibode rẹ.
58 Bi iwọ kò ba fẹ́ kiyesi ati ma ṣe gbo-
gbo ọ̀rọ ofin yi ti a kọ sinu iwé yi, lati ma
bẹ̀ru orukọ yi ti o lí ogo ti o si lí ẹ̀ru, OLU-
WA ỌLỌRUN RẸ ;
59 Njẹ OLUWA yio sọ iyọnu rẹ di iyanu,
ati iyọnu irú-ọmọ rẹ, ani iyọnu nla, ati
eyiti yio pẹ, ati àrun buburu, ati eyiti yio
pẹ.
60 On o si mú gbogbo àrun Egipti pada
wá bá ọ, ti iwọ bẹ̀ru ; nwọn o si lẹ̀ mọ́ ọ.
61 Gbogbo àrun pẹlu, ati gbogbo iyọnu,
ti a kò kọ sinu iwé ofin yi, awọn ni OLUWA
yio múwa bá ọ, titi iwọ o fi run.
62 Diẹ li ẹnyin o si kù ni iye, ẹnyin ti
ẹ ti dabi irawọ oju-ọrun ni ọ̀pọlọpọ : nito-
riti iwọ kò gbà ohùn OLUWA Ọlọrun rẹ gbọ́.
63 Yio si ṣe, bi OLUWA ti yọ̀ sori nyin
lati ṣe nyin ni ire, ati lati sọ nyin di pupọ̀;
bẽni OLUWA yio si yọ̀ si nyin lori lati run
nyin, ati lati pa nyin run ; a o si fà nyin
tu kuro lori ilẹ na ni ibi ti iwọ nlọ lati
gbà a.
64 OLUWA yio si tu ọ ká sinu enia gbo-
gbo, lati opin ilẹ dé opin ilẹ ; nibẹ̀ ni iwọ
o si ma bọ oriṣa ti iwọ ati baba rẹ kò mọ̀
rí, ani igi ati okuta.
65 Ati lãrin orilẹ-ède wọnyi ni iwọ ki
yio ri irọrun, bẽli atẹlẹsẹ̀ rẹ ki yio ri isimi:
ṣugbọn OLUWA yio fi iwarìri àiya, ati oju
jijoro, ati ibinujẹ ọkàn fun ọ :
66 Ẹmi rẹ yio sorọ̀ ni iyemeji li oju rẹ ;
iwọ o si ma bẹ̀ru li oru ati li ọsán, iwọ ki
yio si ní idanilọju ẹmi rẹ.
67 Li owurọ̀ iwọ o wipe, Alẹ iba jẹ́ lẹ !
ati li alẹ iwọ o wipe, Ilẹ iba jẹ́ mọ́ ! nitori
ibẹ̀ru àiya rẹ ti iwọ o ma bẹ̀ru, ati nitori
iran oju rẹ ti iwọ o ma ri.
68 OLUWA yio si fi ọkọ̀ tun mú ọ pada
lọ si Egipti, li ọ̀na ti mo ti sọ fun ọ pe, Iwọ
ki yio si tun ri i mọ́ : nibẹ̀ li ẹnyin o si ma
tà ara nyin fun awọn ọtá nyin li ẹrú ọkọn-
rin ati ẹrú obirin, ki yio si sí ẹniti yio rà
nyin.

## ORI 29.

WỌNYI li ọ̀rọ majẹmu ti OLUWA palaṣẹ
fun Mose lati bá awọn ọmọ Israeli dá
ni ilẹ Moabu, lẹhin majẹmu ti o ti bá wọn
dá ni Horebu.
2 Mose si pè gbogbo awọn ọmọ Israeli, o
si wi fun wọn pe, Ẹnyin ti ri ohun gbogbo
ti OLUWA ṣe li oju nyin ni ilẹ Egipti si
Farao, ati si gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀ ati si
ilẹ rẹ̀ gbogbo.
3 Idanwò nla ti oju rẹ ti ri, iṣẹ-àmi, ati
iṣẹ-iyanu nla wọnni :

Digitized by Google

4 Ṣugbọn OLUWA kò fun nyin li àiya
lati mọ̀, ati oju lati ri, ati etí lati gbọ́ titi
di oni yi.
5 Emi si ti mu nyin rìn li ogoji ọdún li
aginjù: aṣọ nyin kò gbó mọ́ nyin li ara,
bàta rẹ kò si gbó mọ́ ọ li ẹsẹ̀.
6 Ẹnyin kò jẹ àkara, bẹ̃li ẹnyin kò mu
ọti-waini, tabi ọti lile: ki ẹnyin ki o le mọ̀
pe emi li OLUWA Ọlọrun nyin.
7 Nigbati ẹnyin ti dé ihinyi, Sihoni ọba
Hesboni, ati Ogu ọba Baṣani, jade ogun si
wa, awa si kọlù wọn:
8 Awa si gbà ilẹ wọn, a si fi i fun awọn
ọmọ Reubeni, ati awọn ọmọ Gadi, ati àbọ
ẹ̀ya Manasse ni iní.
9 Nitorina, ẹ pa ọ̀rọ majẹmu yi mọ́, ki
ẹ si ma ṣe wọn, ki ẹnyin ki o le ma ri ire
ninu ohun gbogbo ti ẹnyin nṣe.
10 Gbogbo nyin li o duro li oni niwaju
OLUWA Ọlọrun nyin; awọn olori nyin,
awọn ẹ̀ya nyin, awọn àgba nyin, ati awọn
ijoye nyin, ani gbogbo awọn ọkọnrin
Israeli,
11 Awọn ọmọ wẹ́wẹ nyin, awọn aya nyin,
ati alejò rẹ, ti mbẹ lãrin ibudó rẹ, lati aṣẹgi
rẹ dé apọnmi rẹ:
12 Ki iwọ ki o le wọ̀ inu majẹmu OLUWA
Ọlọrun rẹ, ati ibura rẹ̀, ti OLUWA Ọlọrun
rẹ bá ọ ṣe li oni:
13 Ki o le fi idi rẹ kalẹ li oni li enia kan
fun ara rẹ̀, ati ki on ki o le ma ṣe Ọlọrun
rẹ, bi o ti sọ fun ọ, ati bi o ti bura fun
awọn baba rẹ, fun Abrahamu, fun Isaaki,
ati fun Jakobu.
14 Ki si iṣe ẹnyin nikan ni mo bá ṣe
majẹmu yi ati ibura yi;
15 Ṣugbọn ẹniti o bá wa duro nihin li
oni niwaju OLUWA Ọlọrun wa, ẹniti kò sí
nihin pẹlu wa li oni:
16 (Nitoripe ẹnyin mọ̀ bi awa ti gbé ilẹ
Egipti; ati bi awa ti kọja lãrin orilẹ-ède ti
ẹnyin là kọja;
17 Ẹnyin si ti ri ohun irira wọn, ati ere
wọn, igi ati okuta, fadakà ati wurà, ti o
wà lãrin wọn.)
18 Ki ẹnikẹni ki o má ba wà ninu nyin,
ọkọnrin, tabi obirin, tabi idile, tabi ẹ̀ya, ti
àiya rẹ̀ yí kuro lọdọ OLUWA Ọlọrun wa li
oni, lati lọ isìn oriṣa awọn orilẹ-ède wọnyi;
ki gbòngbo ti nyọ orõro ati iwọ, ki o má ba
wà ninu nyin;
19 Yio si ṣe, nigbati o ba gbọ́ ọ̀rọ egún
yi, ti o sure fun ara rẹ̀ ninu àiya rẹ̀, wipe,
Emi o ní alafia, bi emi tilẹ nrìn ninu agídi
ọkàn mi, lati run tutù pẹlu gbigbẹ:
20 OLUWA ki yio darijì i, ṣugbọn nigba-
na ni ibinu OLUWA ati owú rẹ̀ yio gbona si
ọkọnrin na, ati gbogbo egún wọnyi ti a kọ
sinu iwé yi ni yio bà lé e, OLUWA yio si nù
orukọ rẹ̀ kuro labẹ ọrun.
21 OLUWA yio si yà a si ibi kuro ninu
gbogbo ẹ̀ya Israeli, gẹgẹ bi gbogbo egún
majẹmu, ti a kọ sinu iwé ofin yi.
22 Ati iran ti mbọ̀, awọn ọmọ nyin ti
yio dide lẹhin nyin, ati alejò ti yio ti ilẹ
jijìn wá, yio si wi, nigbati nwọn ba ri
iyọnu ilẹ na, ati àrun na, ti OLUWA mu
bá a;
23 Ati pe gbogbo ilẹ rẹ̀ di imi-õrùn, ati
iyọ̀, ati ijóna, ti a kò le gbìn nkan si, tabi
ti kò le seso, tabi ti koriko kò le hù ninu
rẹ̀, bi ibìṣubu Sodomu, ati Gomorra, Adma,
ati Seboiimu, ti OLUWA bìṣubu ninu ibinu
rẹ̀, ati ninu ikannu rẹ̀:
24 Ani gbogbo orilẹ-ède yio ma wipe,
Ẽṣe ti OLUWA fi ṣe bayi si ilẹ yi? Kili a
le mọ̀ õru ibinu nla yi si?
25 Nwọn o si wipe, Nitoriti nwọn kọ̀
majẹmu OLUWA, Ọlọrun awọn baba wọn
silẹ, ti o ti bá wọn dá nigbati o mú wọn
lati ilẹ Egipti jade wá.
26 Nitoriti nwọn lọ nwọn si bọ oriṣa,
nwọn si tẹriba fun wọn, oriṣa ti nwọn kò
mọ̀ rí, ti on kò si fi fun wọn.
27 Ibinu OLUWA si rú si ilẹ na, lati mú
gbogbo egún ti a kọ sinu iwé yi wá sori rẹ̀:
28 OLUWA si fà wọn tu kuro ni ilẹ wọn
ni ibinu, ati ni ikannu, ati ni irunu nla, o
si lé wọn lọ si ilẹ miran, bi o ti ri li oni yi.
29 Ti OLUWA Ọlọrun wa ni ohun ìkọkọ:
ṣugbọn ohun ti afihàn ni ti wa ati ti awọn
ọmọ wa lailai, ki awa ki o le ma ṣe gbogbo
ọ̀rọ ofin yi.

## ORI 30.

YIO si ṣe, nigbati gbogbo nkan wọnyi ba
dé bá ọ, ibukún ati egún, ti mo filelẹ
niwaju rẹ, ti iwọ o ba si ranti ninu gbogbo
orilẹ-ède, nibiti OLUWA Ọlọrun rẹ ti tu ọ
ká si,
2 Ti iwọ ba si yipada si OLUWA Ọlọrun
rẹ, ti iwọ ba si gbà ohùn rẹ̀ gbọ́, gẹgẹ bi
gbogbo eyiti mo filelẹ li aṣẹ fun ọ li oni,
iwọ ati awọn ọmọ rẹ, pẹlu àiya rẹ gbogbo,
ati pẹlu ọkàn rẹ gbogbo;
3 Nigbana ni OLUWA Ọlọrun rẹ yio yi
oko-ẹrú rẹ pada, yio si ṣãnu fun ọ, yio si
pada, yio si kó ọ jọ kuro ninu gbogbo orilẹ-
ède wọnni nibiti OLUWA Ọlọrun rẹ ti tu ọ
ká si.
4 Bi a ba si lé ẹni rẹ kan lọ si ìha opin

Digitized by Google

ọrun, lati ibẹ̀ ni OLUWA Ọlọrun rẹ yio kó ọ jọ, lati ibẹ̀ ni yio si mú ọ wá:

5 OLUWA Ọlọrun rẹ yio si mú ọ wá sinu ilẹ na ti awọn baba rẹ ti ní, iwọ o si ní i; on o si ṣe ọ li ore, yio si mu ọ bisi i jù awọn baba rẹ lọ.

6 OLUWA Ọlọrun rẹ yio si kọ àiya rẹ nilà, ati àiya irú-ọmọ rẹ, lati ma fẹ́ OLUWA Ọlọrun rẹ pẹlu àiya rẹ gbogbo, ati pẹlu ọkàn rẹ gbogbo, ki iwọ ki o le yè.

7 OLUWA Ọlọrun rẹ yio si fi gbogbo egún wọnyi lé awọn ọtá rẹ lori, ati lori awọn ti o korira rẹ, ti nṣe inunibini si ọ.

8 Iwọ o si pada, iwọ o si gbà ohùn OLUWA gbọ́, iwọ o si ma ṣe gbogbo ofin rẹ̀ ti mo palaṣẹ fun ọ li oni.

9 OLUWA Ọlọrun rẹ yio si sọ ọ di pupọ̀ ninu gbogbo iṣẹ ọwọ́ rẹ, ninu ọmọ inu rẹ, ati ninu ohunọ̀sin rẹ, ati ninu eso ilẹ rẹ, fun rere: nitoriti OLUWA yio pada wa yọ̀ sori rẹ fun rere, bi o ti yọ̀ sori awọn baba rẹ:

10 Bi iwọ ba gbà ohùn OLUWA Ọlọrun rẹ gbọ́, lati pa aṣẹ rẹ̀ ati ìlana rẹ̀ mọ́, ti a kọ sinu iwé ofin yi; bi iwọ ba si fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, yipada si OLUWA Ọlọrun rẹ.

11 Nitori aṣẹ yi ti mo pa fun ọ li oni, kò ṣoro jù fun ọ, bẹ̃ni kò jìna rere si ọ.

12 Kò sí li ọrun, ti iwọ iba fi wipe, Tani yio gòke lọ si ọrun fun wa, ti yio si mú u wá fun wa, ki awa ki o le gbọ́ ọ, ki a si le ṣe e?

13 Bẹ̃ni kò sí ni ìha keji okun, ti iwọ iba fi wipe, Tani yio rekọja okun lọ fun wa, ti yio si mú u fun wa wá, ki awa ki o le gbọ́ ọ, ki a si le ṣe e?

14 Ṣugbọn ọ̀rọ na li o wà nitosi rẹ girigiri yi, li ẹnu rẹ, ati li àiya rẹ, ki iwọ ki o le ma ṣe e.

15 Wò o, emi fi ìye ati ire, ati ikú ati ibi, siwaju rẹ li oni;

16 Li eyiti mo palaṣẹ fun ọ li oni lati ma fẹ́ OLUWA Ọlọrun rẹ, lati ma rìn li ọ̀na rẹ̀, ati lati ma pa aṣẹ rẹ̀, ati ìlana rẹ̀, ati idajọ rẹ̀ mọ́, ki iwọ ki o le yè, ki o si ma bisi i, ki OLUWA Ọlọrun rẹ ki o le busi i fun ọ ni ilẹ na, nibiti iwọ nlọ lati gbà a.

17 Ṣugbọn bi àiya rẹ ba pada, ti iwọ kò ba si gbọ́, ṣugbọn ti iwọ di ẹni fifà lọ, ti iwọ si mbọ oriṣa, ti iwọ si nsìn wọn;

18 Emi sọ fun nyin li oni, pe ṣiṣegbé li ẹnyin o ṣegbé; ẹnyin ki yio mu ọjọ́ nyin pẹ lori ilẹ, nibiti iwọ ngòke Jordani lọ lati gbà a.

19 Emi pè ọrun ati ilẹ jẹri tì nyin li oni pe, emi fi ìye ati ikú, ibukún ati egún siwaju rẹ: nitorina yàn ìye, ki iwọ ki o le yè, iwọ ati irú-ọmọ rẹ:

20 Ki iwọ ki o le ma fẹ́ OLUWA Ọlọrun rẹ, ati ki iwọ ki o le ma gbà ohùn rẹ̀ gbọ́, ati ki iwọ ki o le ma faramọ́ ọ: nitoripe on ni ìye rẹ, ati gigùn ọjọ́ rẹ: ki iwọ ki o le ma gbé inu ilẹ na ti OLUWA ti bura fun awọn baba rẹ, fun Abrahamu, ati fun Isaaki, ati fun Jakobu, lati fi fun wọn.

## ORI 31.

MOSE si lọ, o si sọ ọ̀rọ wọnyi fun gbogbo Israeli.

2 O si wi fun wọn pe, Emi di ẹni ọgọfa ọdún li oni; emi kò le ma jade ki nsi ma wọle mọ́: OLUWA si ti wi fun mi pe, Iwọ ki yio gòke Jordani yi mọ́.

3 OLUWA Ọlọrun rẹ, on ni yio rekọja ṣaju rẹ, on ni yio si run orilẹ-ède wọnyi kuro niwaju rẹ, iwọ o si gbà wọn: ati Joṣua, on ni yio gòke ṣaju rẹ, bi OLUWA ti wi.

4 OLUWA yio si ṣe si wọn bi o ti ṣe si Sihoni ati si Ogu, ọba awọn Amori, ati si ilẹ wọn; awọn ẹniti o run.

5 OLUWA yio si fi wọn tọrẹ niwaju nyin, ki ẹnyin ki o le fi wọn ṣe gẹgẹ bi gbogbo aṣẹ ti mo pa fun nyin.

6 Ẹ ṣe giri ki ẹ si mu àiya le, ẹ máṣe bẹru, ẹ má si ṣe fòya wọn: nitoripe OLUWA Ọlọrun rẹ, on li o mbá ọ lọ; on ki yio fi ọ silẹ, bẹ̃ni ki yio kọ̀ ọ.

7 Mose si pè Joṣua, o si wi fun u li oju gbogbo Israeli pe, Ṣe giri ki o si mu àiya le: nitoripe iwọ ni yio bá awọn enia yi lọ si ilẹ na, ti OLUWA ti bura fun awọn baba wọn, lati fi fun wọn; iwọ o si mu wọn gbà a.

8 Ati OLUWA on li o nlọ ṣaju rẹ; on ni yio pẹlu rẹ, on ki yio fi ọ silẹ, bẹ̃ni ki yio kọ̀ ọ: máṣe bẹru, bẹ̃ni ki àiya ki o máṣe fò ọ.

9 Mose si kọwe ofin yi, o si fi i fun awọn alufa awọn ọmọ Lefi, ti ima rù apoti majẹmu OLUWA, ati fun gbogbo awọn àgba Israeli.

10 Mose si paṣẹ fun wọn, wipe, Li opin ọdún meje meje li akokò ọdún idasilẹ, ni ajọ agọ́.

11 Nigbati gbogbo Israeli ba wá farahàn niwaju OLUWA Ọlọrun rẹ ni ibi ti on o gbé yàn, ki iwọ ki o kà ofin yi niwaju gbogbo Israeli li etí wọn.

12 Kó awọn enia na jọ, awọn ọkọnrin ati awọn obirin ati awọn ọmọde, ati alejò rẹ ti mbẹ ninu ibode rẹ, ki nwọn ki o le

Digitized by Google

gbọ́, ati ki nwọn ki o le kọ ati ma bẹ̀ru OLUWA Ọlọrun nyin, ati ki nwọn ki o ma kiyeṣi ati ṣe gbogbo ọ̀rọ ofin yi;

13 Ati ki awọn ọmọ wọn, ti ko mọ̀, ki o le gbọ́, ki nwọn si kọ́ ati bẹ̀ru OLUWA Ọlọrun nyin, ni gbogbo ọjọ́ ti ẹnyin o wà ni ilẹ na nibiti ẹnyin ngòke Jordani lọ lati gbà a.

14 OLUWA si sọ fun Mose pe, Kiyesi i, ọjọ́ rẹ sunmọ-etile ti iwọ o kú: pè Joṣua, ki ẹ si fara nyin hàn ninu agọ́ ajọ, ki emi ki o le fi aṣẹ lé e lọwọ. Mose ati Joṣua si lọ, nwọn si fara wọn hàn ninu agọ́ ajọ.

16 OLUWA si yọ si wọn ninu agọ́ na ninu ọwọ̀n awọsanma: ọwọ̀n awọsanma na si duro loke ẹnu-ọ̀na agọ́ na.

16 OLUWA si sọ fun Mose pe, Kiyesi i, iwọ o sùn pẹlu awọn baba rẹ; awọn enia yi yio si dide, nwọn o si ma ṣe àgbere tọ̀ awọn oriṣa ilẹ na lẹhin, nibiti nwọn nlọ lati gbé inu wọn, nwọn o si kọ̀ mi silẹ, nwọn o si dà majẹmu mi ti mo bá wọn dá.

17 Nigbana ni ibinu mi yio rú si wọn li ọjọ́ na, emi o si kọ̀ wọn silẹ, emi o si pa oju mi mọ́ kuro lara wọn, a o si jẹ wọn run, ati ibi pupọ̀ ati iyọnu ni yio bá wọn; tobẹ̃ ti nwọn o si wi li ọjọ́ na pe, Kò ha jẹ́ pe nitoriti Ọlọrun wa kò sí lãrin wa ni ibi wọnyi ṣe bá wa?

18 Emi o fi oju mi pamọ́ patapata li ọjọ́ na, nitori gbogbo ìwabuburu ti nwọn o ti hù, nitori nwọn yipada si oriṣa.

19 Njẹ nisisiyi, kọwe orin yi fun ara nyin, ki ẹ fi kọ́ awọn ọmọ Israeli: fi i si wọn li ẹnu, ki orin yi ki o le ma jẹ́ ẹrí fun mi si awọn ọmọ Israeli,

20 Nitoripe nigbati emi ba mú wọn wá si ilẹ na, ti mo bura fun awọn baba wọn, ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin; ti nwọn ba si jẹ ajẹyo tán, ti nwọn si sanra; nigbana ni nwọn o yipada si oriṣa, nwọn a si ma sìn wọn, nwọn a si kẹ̀gan mi, nwọn a si dà majẹmu mi.

21 Yio si ṣe, nigbati ibi pupọ̀ ati iyọnu ba bá wọn, ki orin yi ki o jẹri tì wọn bi ẹlẹri; nitoripe a ki yio gbagbé rẹ̀ lati ẹnu awọn ọmọ wọn: nitori mo mọ̀ ìro inu wọn, ti nwọn nrò, ani nisisiyi, ki emi ki o to mú wọn wá sinu ilẹ na ti mo bura si.

22 Nitorina ni Mose ṣe kọwe orin yi li ọjọ́ na gan, o si fi kọ́ awọn ọmọ Israeli.

23 O si paṣẹ fun Joṣua ọmọ Nuni, o si wipe, Ṣe giri, ki o si mu àiya le: nitoripe iwọ ni yio mú awọn ọmọ Israeli lọ sinu ilẹ na ti mo bura fun wọn: Emi o si wà pẹlu rẹ.

24 O si ṣe, nigbati Mose pari kikọ ọ̀rọ ofin yi tán sinu iwé, titi nwọn fi pari,

25 Mose si paṣẹ fun awọn ọmọ Lefi, ti nrù apoti majẹmu OLUWA, wipe,

26 Gbà iwé ofin yi, ki o si fi i sapakan apoti majẹmu OLUWA Ọlọrun rẹ, ki o ma wà nibẹ̀ fun ẹrí si ọ.

27 Nitoripe mo mọ̀ ọ̀tẹ rẹ, ati lile ọrùn rẹ: kiyesi i, nigbati emi wà lãye sibẹ̀ pẹlu nyin li oni, ọlọtẹ̀ li ẹnyin ti nṣe si OLUWA; melomelo si ni lẹhin ikú mi?

28 Pè gbogbo awọn àgba ẹ̀ya nyin jọ sọdọ mi, ati awọn ijoye nyin, ki emi ki o le sọ ọ̀rọ wọnyi li etí wọn ki emi ki o si pè ọrun ati aiye jẹri tì wọn.

29 Nitori mo mọ̀ pe lẹhin ikú mi ẹnyin o bà ara nyin jẹ́ patapata, ati pe ẹnyin o yipada kuro li ọ̀na ti mo palaṣẹ fun nyin; ibi yio si bá nyin li ọjọ́ ikẹhin; nitoriti ẹnyin o ma ṣe buburu li oju OLUWA, lati fi iṣẹ ọwọ́ nyin mu u binu.

30 Mose si sọ ọ̀rọ orin yi li etí gbogbo ijọ Israeli, titi nwọn fi pari.

## ORI 32.

FETISILẸ, ẹnyin ọrun, emi o si sọ̀rọ; si gbọ́ ọ̀rọ ẹnu mi, iwọ aiye:

2 Ẹkọ́ mi yio ma kán bi òjo, ohùn mi yio ma sẹ̀ bi ìri; bi òjo winiwini sara eweko titun, ati bi ọ̀wara òjo sara ewebẹ̀:

3 Nitoriti emi o kokikí orukọ OLUWA kiri: ẹ fi ọlá fun Ọlọrun wa.

4 Apata na, pipé ni iṣẹ rẹ̀; nitoripe idajọ ni gbogbo ọ̀na rẹ̀: Ọlọrun otitọ ati alàiṣegbe, ododo ati otitọ li on.

5 Nwọn ti bà ara wọn jẹ́ lọdọ rẹ̀, nwọn ki iṣe ọmọ rẹ̀, àbukun wọn ni; iran arekereke ati wiwọ́ ni nwọn.

6 Bayi li ẹnyin o ha san ẹsan fun OLUWA, ẹnyin aṣiwere enia ati alaigbọn? On ha kọ́ ni baba rẹ ti o rà ọ? on li o dá ọ, on li o si fi ẹsẹ̀ rẹ mulẹ?

7 Ranti ọjọ́ igbãni, ronu ọdún iraniran: bi baba rẹ lere yio si fihàn ọ; bi awọn àgba rẹ, nwọn o si sọ fun ọ.

8 Nigbati Ọga-ogo pín iní fun awọn orilẹ-ède, nigbati o tu awọn ọmọ enia ká, o pàla awọn enia na gẹgẹ bi iye awọn ọmọ Israeli.

9 Nitoripe ipín ti OLUWA li awọn enia rẹ̀; Jakobu ni ipín iní rẹ̀.

10 O ri i ni ilẹ aṣalẹ̀, ati ni aginju nibiti ẹranko nke; o yi i ká, o tọju rẹ̀, o pa a mọ́ bi ẹyin oju rẹ̀:

11 Bi idì ti irú itẹ́ rẹ̀, ti iràbaba sori ọmọ

Digitized by Google

rẹ̀, ti inà iyẹ́-apa rẹ̀, ti igbé wọn, ti ima gbé
wọn lọ lori iyẹ́-apa rẹ̀ :
12 Bẽni Oluwa nikan ṣamọ̀na rẹ̀, kò si
sí oriṣa pẹlu rẹ̀.
13 O mu u gùn ibi giga aiye, ki o le ma
jẹ eso oko; o si jẹ ki o mu oyin lati inu
apata wá, ati oróro lati inu okuta akọ wá;
14 Ori-amọ́ malu, ati warà agutan, pẹlu
ọrá ọdọ-agutan, ati àgbo irú ti Baṣani, ati
ewurẹ, ti on ti ọrá iwe alikama; iwọ si mu
ẹ̀jẹ eso-àjara, ani ọti-waini.
15 Ṣugbọn Jeṣuruni sanra tán, o si tapa:
iwọ sanra tán, iwọ kì tan, ọrá bò ọ tán:
nigbana li o kọ̀ Ọlọrun ti o dá a, o si gàn
Apata ìgbala rẹ̀.
16 Nwọn fi oriṣa mu u jowú, ohun irira
ni nwọn fi mu u binu.
17 Nwọn rubọ si iwin-buburu ti ki iṣe
Ọlọrun, si oriṣa ti nwọn kò mọ̀ rí, si oriṣa
ti o hù ni titun, ti awọn baba nyin kò
bẹ̀ru.
18 Apata ti o bi ọ ni iwọ kò ranti, iwọ
si ti gbagbé Ọlọrun ti o dá ọ.
19 Oluwa si ri i, o si korira wọn, nitori
ìwa-imunibinu awọn ọmọkọnrin rẹ̀, ati ti
awọn ọmọbirin rẹ̀.
20 O si wipe, Emi o pa oju mi mọ́ kuro
lara wọn, emi o si ma wò bi igbẹhin wọn
yio ti ri; nitori iran agídi ni nwọn, awọn
ọmọ ninu ẹniti kò sí igbagbọ.
21 Nwọn ti fi ohun ti ki iṣe Ọlọrun mu
mi jowú; nwọn si fi ohun asan wọn mu mi
binu: emi o si fi awọn ti ki iṣe enia mu
wọn jowú; emi o si fi aṣiwere orilẹ-ède mu
wọn binu.
22 Nitoripe iná kan ràn ninu ibinu mi,
yio si jó dé ipò-okú ni isalẹ, yio si run aiye
pẹlu asunkún rẹ̀, yio si tinabọ ipilẹ awọn
okenla.
23 Emi o kó ohun buburu jọ lé wọn
lori; emi o si lò ọfà mi tán si wọn lara:
24 Ebi yio mu wọn gbẹ, oru gbigbona li
a o fi run wọn, ati iparun kikorò; emi o si
rán ehín ẹranko si wọn, pẹlu oró ohun ti
nrakò ninu erupẹ.
25 Idà li ode, ati ipàiya ninu iyẹwu, ni
yio run ati ọmọkọnrin ati wundia, ọmọ
ẹnu-ọmu, ati ọkọnrin arugbo elewu irun
pẹlu.
26 Mo wipe, Emi o tu wọn ká patapata,
emi o si mu iranti wọn dá kuro ninu awọn
enia:
27 Bikoṣepe bi mo ti bẹ̀ru ibinu ọtá, ki
awọn ọtá wọn ki o má ba ṣe alaimọ̀, ati ki
nwọn ki o má ba wipe, Ọwọ́ wa leke ni, ki
isi ṣe Oluwa li o ṣe gbogbo eyi.
28 Nitori orilẹ-ède ti kò ní ìmọ ni nwọn,
bẽni kò sí oyé ninu wọn.
29 Ibaṣepe nwọn gbọ́n, ki oyé eyi ki o
yé wọn, nwọn iba rò igbẹhin wọn!
30 Ẹnikan iba ti ṣe lé ẹgbẹrun, ti ẹni
meji iba si lé ẹgbãrun sá, bikoṣepe bi
Apata wọn ti tà wọn, ti Oluwa si fi wọn
tọrẹ?
31 Nitoripe apata wọn kò dabi Apata
wa, ani awọn ọtá wa tikalawọn ni nṣe
onidajọ.
32 Nitoripe igi-àjara wọn, ti igi-àjara
Sodomu ni, ati ti igbẹ́ Gomorra: eso-àjara
wọn li eso-àjara orõro, ìdi wọn korò:
33 Ọti-waini wọn iwọ ti dragon ni, ati
oró mimu ti pamọlẹ.
34 Eyi ki a tojọ sọdọ mi ni ile iṣura, ti
a si fi èdidi dì ninu iṣura mi?
35 Ti emi ni igbẹsan, ati ẹsan, li akokò
ti ẹsẹ̀ wọn yio yọ́: nitoriti ọjọ́ idamu wọn
sunmọtosi, ohun ti o si mbọ̀ wa bá wọn
nyára wá.
36 Nitoripe Oluwa yio ṣe idajọ awọn
enia rẹ̀, yio si kãnu awọn iranṣẹ rẹ̀; nigbati
o ba ri pe agbara wọn lọ tán, ti kò si sí
ẹnikan ti a sé mọ́, tabi ti o kù.
37 On o si wipe, Nibo li oriṣa wọn gbé
wà, apata ti nwọn gbẹkẹle:
38 Ti o ti jẹ ọrá ẹbọ wọn, ti o ti mu ọti-
waini ẹbọ ohunmimu wọn? jẹ ki nwọn
dide ki nwọn si ràn nyin lọwọ, ki nwọn ṣe
àbo nyin.
39 Wò o nisisiyi pe Emi, ani Emi ni, kò
si sí Ọlọrun pẹlu mi: mo pa, mo si sọ di
ãye; mo ṣalọgbẹ, mo si mu jiná; kò si sí
ẹnikan ti o le gbà silẹ li ọwọ́ mi.
40 Nitoripe mo gbé ọwọ́ mi soke ọrun,
mo si wipe, Bi Emi ti wà titilai.
41 Bi mo ba si pọ́n idà didan mi, ti mo
ba si fi ọwọ́ mi lé idajọ; emi o san ẹsan
fun awọn ọtá mi, emi o radi i fun awọn ti
o korira mi.
42 Emi o mu ọfà mi rin fun ẹ̀jẹ, idà mi
o si jẹ ẹran; ninu ẹ̀jẹ ẹni pipa ati ti igbe-
kun, lati ori awọn aṣaju ọtá.
43 Ẹ ma yọ̀, ẹnyin orilẹ-ède, pẹlu awọn
enia rẹ̀: nitoripe on o gbẹsan ẹ̀jẹ awọn
iranṣẹ rẹ̀, yio si gbẹsan lara awọn ọtá rẹ̀,
yio si ṣètutu fun ilẹ rẹ̀, ati fun awọn
enia rẹ̀.
44 Mose si wá, o si sọ gbogbo ọ̀rọ ofin yi
li etí awọn enia na, on, ati Hoṣea ọmọ
Nuni.
45 Mose si pari sisọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi
fun gbogbo Israeli:
46 O si wi fun wọn pe, Ẹ gbé ọkàn nyin

Digitized by Google

lé gbogbo ọ̀rọ ti mo sọ lãrin nyin li oni; ti ẹnyin o palaṣẹ fun awọn ọmọ nyin lati ma kiyesi ati ṣe gbogbo ọ̀rọ ofin yi.
47 Nitoripe ki iṣe ohun asan fun nyin; nitoripe ìye nyin ni, ati nipa eyi li ẹnyin o mu ọjọ́ nyin pẹ ni ilẹ na, nibiti ẹnyin ngòke Jordani lọ lati gbà a.
48 OLUWA si sọ fun Mose li ọjọ́ na gan, wipe,
49 Gùn òke Abarimu yi lọ, si òke Nebo, ti mbẹ ni ilẹ Moabu, ti o kọjusi Jeriko; ki o si wò ilẹ Kenaani, ti mo fi fun awọn ọmọ Israeli ni iní.
50 Ki o si kú lori òke na, nibiti iwọ ngùn lọ, ki a si kó ọ jọ sọdọ awọn enia rẹ; bi Aaroni arakọnrin rẹ ti kú li òke Horu, ti a si kó o jọ sọdọ awọn enia rẹ̀:
51 Nitoriti ẹnyin ṣẹ̀ si mi lãrin awọn ọmọ Israeli ni ibi omi Meriba-Kadeṣi, li aginjù Sini; nitoriti ẹnyin kò yà mi simimọ́ lãrin awọn ọmọ Israeli.
52 Ṣugbọn iwọ o ri ilẹ na niwaju rẹ; ṣugbọn iwọ ki yio lọ sibẹ̀, si ilẹ na ti mo fi fun awọn ọmọ Israeli.

## ORI 33.

EYI si ni ire, ti Mose enia Ọlọrun su fun awọn ọmọ Israeli ki o to kú.
2 O si wipe, OLUWA ti Sinai wá, o si yọ si wọn lati Seiri wá; o tàn imọlẹ jade lati òke Parani wá, o ti ọdọ ẹgbẹgbãrun awọn mimọ́ wá: lati ọwọ́ ọtún rẹ̀ li ofin kan amubina ti jade fun wọn wá.
3 Nitõtọ, o fẹ́ awọn enia na; gbogbo awọn enia mimọ́ rẹ̀ wà li ọwọ́ rẹ. Nwọn si joko li ẹsẹ̀ rẹ; olukuluku ni yio gbà ninu ọ̀rọ rẹ.
4 Mose fi ofin kan lelẹ li aṣẹ fun wa, iní ti ijọ enia Jakobu.
5 O si jẹ́ ọba ni Jeṣuruni, nigbati olori awọn enia, awọn ẹ̀ya Israeli pejọ pọ̀.
6 Ki Reubeni ki o yè, ki o máṣe kú; ki enia rẹ̀ ki o máṣe mọniwọn.
7 Eyi si ni ti Juda: o si wipe, OLUWA, gbọ́ ohùn Juda, ki o si mú u tọ̀ awọn enia rẹ̀ wá: ki ọwọ́ rẹ̀ ki o to fun u; ki iwọ ki o si ṣe iranlọwọ fun u lọwọ awọn ọtá rẹ̀.
8 Ati niti Lefi o wipe, Jẹ ki Tummimu ati Urimu rẹ ki o wà pẹlu ẹni mimọ́ rẹ, ẹniti iwọ danwò ni Massa, ati ẹniti iwọ bájà li omi Meriba;
9 Ẹniti o wi niti baba rẹ̀ ati niti iya rẹ̀ pe, Emi kò ri i; bẹ̃ni kò si jẹwọ awọn arakọnrin rẹ̀, bẹ̃ni kò si mọ̀ awọn ọmọ rẹ̀: nitoriti nwọn kiyesi ọ̀rọ rẹ, nwọn si pa majẹmu rẹ mọ́.
10 Nwọn o ma kọ́ Jakobu ni idajọ rẹ, ati Israeli li ofin rẹ; nwọn o ma mú turari wá siwaju rẹ, ati ọ̀tọtọ ẹbọ sisun sori pẹpẹ rẹ.
11 OLUWA, busi ohun-iní rẹ̀, ki o si tẹwọgbà iṣẹ ọwọ́ rẹ̀: lù ẹgbẹ́ awọn ti o dide si i, ati ti awọn ti o korira rẹ̀, ki nwọn ki o máṣe dide mọ́.
12 Ati niti Benjamini o wipe, Olufẹ OLUWA yio ma gbé li alafia lọdọ rẹ̀; On a ma bò o li ọjọ́ gbogbo, on a si ma gbé lãrin ejika rẹ̀.
13 Ati niti Josefu o wipe, Abukún OLUWA ni ilẹ rẹ̀, fun ohun iyebiye ọrun, fun ìri, ati fun ibú ti o ba nisalẹ,
14 Ati fun eso iyebiye ti õrùn múwa, ati fun ohun iyebiye ti ndàgba li oṣoṣù,
15 Ati fun ohun pàtaki okenla igbãni, ati fun ohun iyebiye òke aiyeraiye,
16 Ati fun ohun iyebiye aiye ati ẹkún rẹ̀, ati fun ifẹ́ inurere ẹniti o gbé inu igbẹ́: jẹ ki ibukún ki o wá si ori Josefu, ati si atari ẹniti a yàsọtọ lãrin awọn arakọnrin rẹ̀.
17 Akọ́bi akọmalu rẹ̀, tirẹ̀ li ọlánla; iwo rẹ̀ iwo agbanrere ni: on ni yio fi tì awọn enia, gbogbo wọn, ani opin ilẹ: awọn si ni ẹgbẹgbãrun Efraimu, awọn si ni ẹgbẹgbẹrun Manasse.
18 Ati niti Sebuluni o wipe, Sebuluni, ma yọ̀ ni ijade rẹ; ati Issakari, ninu agọ́ rẹ.
19 Nwọn o pè awọn enia na sori òke; nibẹ̀ ni nwọn o ru ẹbọ ododo: nitoripe nwọn o ma mu ninu ọ̀pọlọpọ okun, ati ninu iṣura ti a pamọ́ ninu iyanrin.
20 Ati niti Gadi o wipe, Ibukún ni fun ẹniti o mu Gadi gbilẹ: o ba bi abokiniun, o si fà apa ya ani atari.
21 O si yàn apá ikini fun ara rẹ̀, nitoripe nibẹ̀ li a fi ipín olofin pamọ́ si; o si wá pẹlu awọn olori enia na, o si mú ododo OLUWA ṣẹ, ati idajọ rẹ̀ pẹlu Israeli.
22 Ati niti Dani o wipe, Ọmọ kiniun ni Dani: ti nfò lati Baṣani wá.
23 Ati niti Naftali o wipe, Iwọ Naftali, ti ojurere tẹ́lọrùn, ti o si kún fun ibukún OLUWA: gbà ìha ìwọ-õrùn ati gusù.
24 Ati niti Aṣeri o wipe, Ibukún ọmọ niti Aṣeri; ki on ki o si jẹ́ itẹwọgba fun awọn arakọnrin rẹ̀, ki on ki o si ma rì ẹsẹ̀ rẹ̀ sinu oróro.
25 Bàta rẹ yio jasi irin ati idẹ; ati bi ọjọ́ rẹ, bẹ̃li agbara rẹ yio ri.
26 Kò sí ẹniti o dabi Ọlọrun, iwọ Jeṣuruni, ti ngùn ọrun fun iranlọwọ rẹ, ati ninu ọlanla rẹ̀ li oju-ọrun.

Digitized by Google

27 Ọlọrun aiyeraiye ni ibugbé rẹ, ati nisalẹ li apa aiyeraiye wà: on si tì ọtá kuro niwaju rẹ, o si wipe, Ma parun.
28 Israeli si joko li alafia, orisun Jakobu nikan, ni ilẹ ọkà ati ti ọtiwaini; pẹlupẹlu ọrun rẹ̀ nsẹ̀ ìri silẹ.
29 Alafia ni fun iwọ, Israeli: tali o dabi rẹ, iwọ enia ti a ti ọwọ́ OLUWA gbàla, asà iranlọwọ rẹ, ati ẹniti iṣe idà ọlanla rẹ! awọn ọtá rẹ yio si tẹriba fun ọ; iwọ o si ma tẹ̀ ibi giga wọn mọlẹ.

ORI 34.

MOSE si gòke lati pẹtẹlẹ̀ Moabu lọ si òke Nebo, si ori Pisga, ti o dojukọ Jeriko. OLUWA si fi gbogbo ilẹ Gileadi dé Dani hàn a;
2 Ati gbogbo Naftali, ati ilẹ Efraimu, ati ti Manasse, ati gbogbo ilẹ Juda, dé okun ìwọ-õrùn;
3 Ati gusù, ati pẹtẹlẹ̀ afonifoji Jeriko, ilu ọlọpẹ dé Soari.
4 OLUWA si wi fun u pe, Eyi ni ilẹ ti mo bura fun Abrahamu, fun Isaaki, ati fun Jakobu, wipe, Emi o fi i fun irú-ọmọ rẹ: emi mu ọ fi oju rẹ ri i, ṣugbọn iwọ ki yio rekọja lọ sibẹ̀.
5 Bẽni Mose iranṣẹ OLUWA kú nibẹ̀ ni ilẹ Moabu, gẹgẹ bi ọ̀rọ OLUWA.
6 O si sin i ninu afonifoji ni ilẹ Moabu, ti o kọjusi Beti-peori; ṣugbọn kò sí ẹnikan ti o mọ̀ iboji rẹ̀ titi di oni-oloni.
7 Mose si jẹ́ ẹni ọgọfa ọdún nigbati o kú: oju rẹ̀ kò ṣe baìbai, bẽli agbara rẹ̀ kò dinku.
8 Awọn ọmọ Israeli si sọkun Mose ni pẹtẹlẹ̀ Moabu li ọgbọ̀n ọjọ́: bẽli ọjọ́ ẹkún ati ọ̀fọ Mose pari.
9 Joṣua ọmọ Nuni si kún fun ẹmi ọgbọ́n; nitoripe Mose ti fi ọwọ́ rẹ̀ lé e lori: awọn ọmọ Israeli si gbà tirẹ̀ gbọ́, nwọn si ṣe bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose.
10 Wolĩ kan kò si hù mọ́ ni Israeli bi Mose, ẹniti OLUWA mọ̀ li ojukoju,
11 Ni gbogbo iṣẹ-àmi ati iṣẹ-iyanu, ti OLUWA rán a lati ṣe ni ilẹ Egipti, si Farao, ati si gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀, ati si gbogbo ilẹ rẹ̀;
12 Ati ni gbogbo ọwọ́ agbara, ati ni gbogbo ẹ̀ru nla ti Mose fihàn li oju gbogbo Israeli.

# IWE JOṢUA.

ORI 1.

O SI ṣe lẹhin ikú Mose iranṣẹ OLUWA, li OLUWA sọ fun Joṣua ọmọ Nuni, iranṣẹ Mose, wipe,
2 Mose iranṣẹ mi kú; njẹ iwọ, dide, gòke Jordani yi, iwọ, ati gbogbo enia yi, si ilẹ ti mo fi fun wọn, ani fun awọn ọmọ Israeli.
3 Ibi gbogbo ti atẹlẹsẹ̀ nyin ba tẹ̀, ẹnyin ni mo fi fun, gẹgẹ bi mo ti sọ fun Mose.
4 Lati aginjù, ati Lebanoni yi, ani titi dé odò nla nì, odò Euferate, gbogbo ilẹ awọn Hitti, ati titi dé okun nla ni ìwọ-õrùn, eyi ni yio ṣe opin ilẹ nyin.
5 Ki yio sí ọkọnrin kan ti yio le duro niwaju rẹ li ọjọ́ aiye rẹ gbogbo: gẹgẹ bi mo ti wà pẹlu Mose, bẽli emi o si wà pẹlu rẹ: Emi ki yio fi ọ silẹ, bẽli emi ki yio kọ̀ ọ.
6 Ṣe giri, ki o si mu àiya le: nitori iwọ ni yio pín ilẹ na fun awọn enia yi, ilẹ ti mo ti bura fun awọn baba wọn lati fi fun wọn.
7 Sá ṣe giri ki o si mu àiya le gidigidi, ki iwọ ki o le kiyesi ati ṣe gẹgẹ bi gbogbo ofin ti Mose iranṣẹ mi ti palaṣẹ fun ọ: má ṣe yà kuro ninu rẹ̀ si ọtún tabi si òsi, ki o le dara fun ọ nibikibi ti iwọ ba lọ.
8 Iwé ofin yi kò gbọdọ kuro li ẹnu rẹ, ṣugbọn iwọ o ma ṣe àṣaro ninu rẹ̀ li ọsán ati li oru, ki iwọ ki o le kiyesi ati ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti a kọ sinu rẹ̀: nitori nigbana ni yio si dara fun ọ.
9 Emi kò ha paṣẹ fun ọ bi? Ṣe giri ki o si mu àiya le; máṣe bẹru, bẽni ki àiya ki o máṣe fò ọ: nitoripe OLUWA Ọlọrun rẹ wà pẹlu rẹ nibikibi ti iwọ ba nlọ.
10 Nigbana ni Joṣua paṣẹ fun awọn olori awọn enia wipe,
11 Ẹ là ãrin ibudó já, ki ẹ si paṣẹ fun awọn enia, wipe, Ẹ pèse onjẹ; nitoripe ni ijọ́ mẹta oni ẹnyin o gòke Jordani yi, lati

Digitized by Google

lọ gbà ilẹ ti OLUWA Ọlọrun nyin fi fun nyin
lati ní.
12 Ati fun awọn ọmọ Reubeni, ati fun
awọn ọmọ Gadi, ati fun àbọ ẹ̀ya Manasse,
ni Joṣua wipe,
13 Ranti ọ̀rọ ti Mose iranṣẹ OLUWA
palaṣẹ fun nyin pe, OLUWA Ọlọrun nyin
nfun nyin ni isimi, on o si fun nyin ni ilẹ
yi.
14 Awọn obirin nyin, ati awọn ọmọ
wẹrẹ nyin, ati ohunọ̀sin nyin, yio joko ni
ilẹ ti Mose fi fun nyin ni ìha ihin Jordani;
ṣugbọn ẹnyin o gòke lọ niwaju awọn ara-
kọnrin nyin ni ihamọra, gbogbo awọn ala-
gbara akọni, ẹnyin o si ràn wọn lọwọ.
15 Titi OLUWA yio fi fun awọn arakọn-
rin nyin ni isimi, gẹgẹ bi o ti fi fun nyin,
ati ti awọn pẹlu yio fi gbà ilẹ na ti OLUWA
Ọlọrun nyin fi fun wọn; nigbana li ẹnyin
o pada si ilẹ iní nyin, ti Mose iranṣẹ OLU-
WA fi fun nyin ni ìha ihin Jordani ni ìha
ìla-õrùn, ẹnyin o si ní i.
16 Nwọn si da Joṣua lohùn, wipe, Gbo-
gbo ohun ti iwọ palaṣẹ fun wa li awa o ṣe,
ibikibi ti iwọ ba rán wa lọ, li awa o lọ.
17 Gẹgẹ bi awa ti gbọ́ ti Mose li ohun
gbogbo, bẹ̃li awa o gbọ́ tirẹ: kìki ki OLUWA
Ọlọrun rẹ ki o wà pẹlu rẹ, gẹgẹ bi o ti wà
pẹlu Mose.
18 Ẹnikẹni ti o wù ki o ṣe ti o ba tapá
si ofin rẹ, ti ki yio si gbọ́ ọ̀rọ rẹ li ohun
gbogbo ti iwọ palaṣẹ fun u, pipa li a o pa
a: kìki ki iwọ ṣe giri ki o si mu àiya le.

## ORI 2.

JOṢUA ọmọ Nuni si rán ọkọnrin meji
jade lati Ṣittimu yọ lọ ṣe amí, wipe, Ẹ
lọ iwò ilẹ na, ati Jeriko. Nwọn si lọ, nwọn
si dé ile panṣaga kan, ti a npè ni Rahabu,
nwọn si wọ̀ nibẹ̀.
2 A si sọ fun ọba Jeriko pe, Kiyesi i,
awọn ọkọnrin kan ninu awọn ọmọ Israeli
dé ihinyi li alẹ yi lati rìn ilẹ yi wò.
3 Ọba Jeriko si ranṣẹ si Rahabu, wipe,
Mú awọn ọkọnrin nì ti o tọ̀ ọ wá, ti o wọ̀
inu ile rẹ jade wá: nitori nwọn wá lati rìn
gbogbo ilẹ yi wò.
4 Obirin na si mú awọn ọkọnrin meji na,
o si fi wọn pamọ́; o si wi bayi pe, Awọn
ọkọnrin kan wá sọdọ mi, ṣugbọn emi kò
mọ̀ ibi ti nwọn ti wá.
5 O si ṣe li akokò ati tì ilẹkun ẹnubode,
nigbati ilẹ ṣú, awọn ọkọnrin na si jade lọ:
ibi ti awọn ọkọnrin na gbé lọ, emi kò mọ̀:
ẹ lepa wọn kánkán; nitori ẹnyin o bá wọn.
6 Ṣugbọn o ti mú wọn gòke àja ile, o si
fi poroporo ọ̀gbọ ti o ti tòjọ soke àja bò wọn
mọlẹ.
7 Awọn ọkọnrin na lepa wọn li ọ̀na ti o
lọ dé iwọ̀do Jordani: bi awọn ti nlepa wọn
si ti jade lọ, nwọn tì ilẹkun ẹnubode.
8 Ki nwọn ki o tó dubulẹ, o gòke tọ̀ wọn
lọ loke àja;
9 O si wi fun awọn ọkọnrin na pe, Emi
mọ̀ pe OLUWA ti fun nyin ni ilẹ yi, ati pe
ẹ̀ru nyin bà ni, ati pe ọkàn gbogbo awọn
ara ilẹ yi di omi nitori nyin.
10 Nitoripe awa ti gbọ́ bi OLUWA ti mu
omi Okun Pupa gbẹ niwaju nyin, nigbati
ẹnyin jade ni Egipti; ati ohun ti ẹnyin ṣe
si awọn ọba meji ti awọn Amori, ti mbẹ ni
ìha keji Jordani, Sihoni ati Ogu, ti ẹnyin
parun tũtu.
11 Lọgán bi awa ti gbọ́ nkan wọnyi,
àiya wa já, bẹ̃ni kò si sí agbara kan ninu
ọkọnrin kan mọ́ nitori nyin; nitoripe
OLUWA Ọlọrun nyin, on li Ọlọrun loke
ọrun, ati nisalẹ aiye.
12 Njẹ nitorina, emi bẹ̀ nyin, ẹ fi OLU-
WA bura fun mi, bi mo ti ṣe nyin li ore,
ẹnyin o ṣe ore pẹlu fun ile baba mi, ẹnyin
o si fun mi li àmi otitọ:
13 Ati pe ẹnyin o pa baba mi mọ́ lãye,
ati iya mi, ati awọn arakọnrin mi, ati
awọn arabirin mi, ati ohun gbogbo ti
nwọn ní, ki ẹnyin si gbà ẹmi wa lọwọ ikú.
14 Awọn ọkọnrin na da a lohùn pe, Ẹmi
wa ni yio dipò ti nyin, bi ẹnyin kò ba fi
ọ̀ran wa yi hàn; yio si ṣe, nigbati OLUWA
ba fun wa ni ilẹ na, awa o ṣe ore ati otitọ
fun ọ.
15 Nigbana li o fi okùn sọ̀ wọn kalẹ li
oju-ferese: nitoriti ile rẹ̀ wà lara odi ilu,
on a si ma gbé ori odi na.
16 O si wi fun wọn pe, Ẹ bọ sori òke,
ki awọn alepa ki o má ba le nyin bá; ki
ẹnyin si fara nyin pamọ́ nibẹ̀ ni ijọ́ mẹta,
titi awọn alepa yio fi pada: lẹhin na ẹ ma
ba ọ̀na ti nyin lọ.
17 Awọn ọkọnrin na wi fun u pe, Ara
wa o dá niti ibura rẹ yi, ti iwọ mu wa bú.
18 Kiyesi i, nigbati awa ba dé inu ilẹ
na, iwọ o so okùn owú ododó yi si oju-
ferese ti iwọ fi sọ̀ wa kalẹ: iwọ o si mú
baba rẹ, ati iya rẹ, ati awọn arakọnrin rẹ,
ati gbogbo ará ile baba rẹ, wá ile sọdọ rẹ.
19 Yio si ṣe, ẹnikẹni ti o ba jade lati inu
ilẹkun ile rẹ lọ si ode, ẹ̀jẹ rẹ̀ yio wà li ori
ara rẹ̀, awa o si wà li aijẹbi: ati ẹnikẹni ti
o ba wà pẹlu rẹ ni ile, ẹ̀jẹ rẹ̀ yio wà li ori
wa, bi ẹnikẹni ba fọwọkàn a.
20 Bi o ba si sọ ọ̀ran wa yi, nigbana ni

Digitized by Google

ara wa o dá niti ibura rẹ ti iwọ mu wa bú
yi.
21 O si wipe, Gẹgẹ bi ọ̀rọ nyin, bẽni ki
o ri. O si rán wọn lọ, nwọn si lọ: o si so
okùn ododó na si oju-ferese.
22 Nwọn si lọ, nwọn si dé ori òke, nwọn
si gbé ibẹ̀ ni ijọ́ mẹta, titi awọn alepa fi
pada: awọn alepa wá wọn ni gbogbo ọ̀na,
ṣugbọn nwọn kò ri wọn.
23 Bẽli awọn ọkọnrin meji na pada,
nwọn si sọkalẹ lori òke, nwọn si kọja,
nwọn si tọ̀ Joṣua ọmọ Nuni wá; nwọn si
sọ ohun gbogbo ti o bá wọn fun u.
24 Nwọn si wi fun Joṣua pe, Nitõtọ li
OLUWA ti fi gbogbo ilẹ na lé wa lọwọ; ni-
toripe ọkàn gbogbo awọn ara ilẹ yi di omi
nitori wa.

## ORI 3.

JOṢUA si dide ni kùtukutu owurọ̀, nwọn
si ṣí kuro ni Ṣittimu, nwọn si dé Jor-
dani, on ati gbogbo awọn ọmọ Israeli;
nwọn si sùn sibẹ̀ ki nwọn ki o to gòke odò.
2 O si ṣe lẹhin ijọ́ mẹta, ni awọn olori
là ãrin ibudó já;
3 Nwọn si paṣẹ fun nwọn enia, wipe,
Nigbati ẹnyin ba ri apoti majẹmu OLUWA
Ọlọrun nyin, ti ẹ ba si ri awọn alufa awọn
ọmọ Lefi rù u, nigbana li ẹnyin o ṣí kuro ni
ipò nyin, ẹnyin o si ma tọ̀ ọ lẹhin.
4 Ṣugbọn alafo yio wà li agbedemeji ti
ẹnyin tirẹ̀, to bi ìwọn ẹgbã igbọnwọ: ẹ má
ṣe sunmọ ọ, ki ẹnyin ki o le mọ̀ ọ̀na ti ẹnyin
o gbà; nitoriti ẹnyin kò gbà ọ̀na yi rí.
5 Joṣua si wi fun awọn enia pe, Ẹ yà
ara nyin simimọ́: nitori li ọla OLUWA yio
ṣe ohun iyanu lãrin nyin.
6 Joṣua si wi fun awọn alufa pe, Ẹ gbé
apoti majẹmu na, ki ẹ si kọja siwaju awọn
enia. Nwọn si gbé apoti majẹmu na,
nwọn si ṣaju awọn enia.
7 OLUWA si wi fun Joṣua pe, Li oni yi
li emi o bẹ̀rẹsi gbé ọ ga li oju gbogbo Israeli,
ki nwọn ki o le mọ̀ pe, gẹgẹ bi mo ti wà
pẹlu Mose, bẽli emi o wà pẹlu rẹ.
8 Iwọ o si paṣẹ fun awọn alufa ti o rù
apoti majẹmu na pe, Nigbati ẹnyin ba dé
eti odò Jordani, ki ẹnyin ki o duro jẹ ni
Jordani.
9 Joṣua si wi fun awọn ọmọ Israeli pe, Ẹ
sunmọ ihin, ki ẹ si gbọ́ ọ̀rọ OLUWA Ọlọrun
nyin.
10 Joṣua si wipe, Nipa eyi li ẹnyin o mọ̀
pe Ọlọrun alãye mbẹ lãrin nyin, ati pe
dajudaju on o lé awọn ara Kenaani, ati
awọn Hitti, ati awọn Hifi, ati awọn Perissi,
ati awọn Girgaṣi, ati awọn Amori, ati awọn
Jebusi, kuro niwaju nyin.
11 Kiyesi i, apoti majẹmu OLUWA gbo-
gbo aiye ngòke lọ ṣaju nyin lọ si Jordani.
12 Njẹ nitorina, ẹ mu ọkọnrin mejila
ninu awọn ẹ̀ya Israeli, ọkọnrin kan ninu
olukuluku ẹ̀ya.
13 Yio si ṣe, lojukanna bi atẹlẹsẹ̀ awọn
alufa ti o rù apoti OLUWA, Oluwa gbogbo
aiye, ba ti tẹ̀ omi Jordani omi Jordani yio
ke kuro, ani omi ti nti òke ṣànwá; yio si
duro bi òkiti kan.
14 O si ṣe, nigbati awọn enia ṣí kuro
ninu agọ́ wọn, lati gòke Jordani, ti awọn
alufa si rù apoti majẹmu wà niwaju awọn
enia;
15 Bi awọn ti o rù apoti si ti dé Jordani,
ti awọn alufa ti o rù apoti na si tẹ̀ ẹsẹ̀ wọn
bọ̀ eti omi na, (nitoripe odò Jordani a ma
kún bò gbogbo bèbe rẹ̀ ni gbogbo akokò
ikore,)
16 Ni omi ti nti oke ṣàn wá duro, o si
ga jìna rére bi òkiti li ọnà ni ilu Adamu,
ti o wà lẹba Saretani: eyiti o si ṣàn sodò
si ìha okun pẹtẹlẹ̀, ani Okun Iyọ̀, a ke wọn
kuro patapata: awọn enia si gòke tara si
Jeriko.
17 Awọn alufa ti o rù apoti majẹmu
OLUWA, si duro ṣinṣin lori ilẹ gbigbẹ lãrin
Jordani, ati gbogbo awọn enia Israeli kọja
lori ilẹ gbigbẹ, titi gbogbo awọn enia na fi
gòke Jordani tán.

## ORI 4.

O SI ṣe, nigbati gbogbo awọn enia rekọja
Jordani tán, ni OLUWA wi fun Joṣua
pe,
2 Mú ọkọnrin mejila ninu awọn enia,
ọkọnrin kan ninu olukuluku ẹ̀ya,
3 Ki ẹnyin si paṣẹ fun wọn pe, Ẹ gbé
okuta mejila lati ihin lọ lãrin Jordani, ni
ibi ti ẹsẹ̀ awọn alufa gbé duro ṣinṣin nì, ki
ẹnyin ki o si rù wọn kọja pẹlu nyin, ẹ si
fi wọn si ibùsun, ni ibi ti ẹnyin o sùn li
alẹ yi.
4 Nigbana ni Joṣua pè awọn ọkọnrin
mejila, ti o ti pèsesilẹ ninu awọn ọmọ
Israeli, ọkọnrin kan ninu olukuluku ẹ̀ya:
5 Joṣua si wi fun wọn pe, Ẹ kọja lọ
niwaju apoti OLUWA Ọlọrun nyin si ãrin
Jordani, ki olukuluku ninu nyin ki o gbé
okuta kọkan lé ejika rẹ̀, gẹgẹ bi iye ẹ̀ya
awọn ọmọ Israeli:
6 Ki eyi ki o le jẹ́ àmi lãrin nyin, ni-
gbati awọn ọmọ nyin ba bère lọwọ awọn

Digitized by Google

baba wọn lẹhinọla, wipe, Ẽredi okuta
wọnyi?
7 Nigbana li ẹnyin o da wọn lohùn pe,
Nitori a ke omi Jordani niwaju apoti ma-
jẹmu OLUWA; nigbati o rekọja Jordani, a
ke omi Jordani kuro: okuta wọnyi yio si
jasi iranti fun awọn ọmọ Israeli lailai.
8 Awọn ọmọ Israeli si ṣe gẹgẹ bi Joṣua
ti paṣẹ, nwọn si gbé okuta mejila lati inu
ãrin Jordani lọ, bi OLUWA ti wi fun Joṣua,
gẹgẹ bi iye ẹ̀ya awọn ọmọ Israeli; nwọn si
rù wọn kọja pẹlu wọn lọ si ibùsun, nwọn
si gbé wọn kalẹ nibẹ̀.
9 Joṣua si tò okuta mejila jọ lãrin
Jordani, ni ibi ti ẹsẹ̀ awọn alufa ti o rù
apoti majẹmu na gbé duro: nwọn si mbẹ
nibẹ̀ titi di oni-oloni.
10 Nitoriti awọn alufa ti o rù apoti na
duro lãrin Jordani, titi ohun gbogbo fi pari
ti OLUWA palaṣẹ fun Joṣua lati sọ fun
awọn enia, gẹgẹ bi gbogbo eyiti Mose pa-
laṣẹ fun Joṣua: awọn enia na si yára nwọn
si rekọja.
11 O si ṣe, nigbati gbogbo awọn enia na
rekọja tán, ni apoti OLUWA rekọja, ati
awọn alufa, li oju awọn enia.
12 Awọn ọmọ Reubeni, ati awọn ọmọ
Gadi, ati àbọ ẹ̀ya Manasse, si rekọja ni
ihamọra niwaju awọn ọmọ Israeli, gẹgẹ bi
Mose ti sọ fun wọn:
13 Ìwọn ọkẹ meji enia ti o mura ogun,
rekọja niwaju OLUWA fun ogun, si pẹtẹlẹ̀
Jeriko.
14 Li ọjọ́ na OLUWA gbé Joṣua ga li oju
gbogbo Israeli: nwọn si bẹ̀ru rẹ̀ gẹgẹ bi
nwọn ti bẹ̀ru Mose li ọjọ́ aiye rẹ̀ gbogbo.
15 OLUWA si wi fun Joṣua pe,
16 Paṣẹ fun awọn alufa ti o rù apoti ẹri
nì pe, ki nwọn ki o ti inu Jordani jade.
17 Nitorina Joṣua paṣẹ fun awọn alufa
wipe, Ẹ ti inu Jordani jade.
18 O si ṣe, nigbati awọn alufa ti o rù
apoti majẹmu OLUWA ti ãrin Jordani jade,
ti awọn alufa si gbé atẹlẹsẹ̀ wọn soke si ilẹ
gbigbẹ, ni omi Jordani pada si ipò rẹ̀, o si
ṣàn bò gbogbo bèbe rẹ̀, gẹgẹ bi ti iṣaju.
19 Awọn enia si ti inu Jordani gòke ni
ijọ́ kẹwa oṣù kini, nwọn si dó ni Gilgali, ni
ìha ìla-õrùn Jeriko.
20 Ati okuta mejila wọnni ti nwọn gbé
ti inu Jordani lọ, ni Joṣua tòjọ ni Gilgali.
21 O si wi fun awọn ọmọ Israeli pe,
Nigbati awọn ọmọ nyin yio bère lọwọ awọn
baba wọn lẹhinọla wipe, Ẽredi okuta
wọnyi?
22 Nigbana li ẹnyin o jẹ ki awọn ọmọ
nyin ki o mọ̀ pe, Israeli là Jordani yi koja
ni ilẹ gbigbẹ.
23 Nitoriti OLUWA Ọlọrun nyin mu omi
Jordani gbẹ kuro niwaju nyin, titi ẹnyin
fi là a kọja, gẹgẹ bi OLUWA Ọlọrun nyin ti
ṣe si Okun Pupa, ti o mu gbẹ kuro niwaju
wa, titi awa fi là a kọja:
24 Ki gbogbo enia aiye ki o le mọ ọwọ́
OLUWA, pe o lagbara; ki nwọn ki o le ma
bẹ̀ru OLUWA Ọlọrun nyin lailai.

## ORI 5.

O SI ṣe, nigbati gbogbo awọn ọba Amori,
ti o wà ni ìha keji Jordani ni ìwọ-
õrùn, ati gbogbo awọn ọba Kenaani ti mbẹ
leti okun, gbọ́ pe OLUWA ti mu omi Jorda-
ni gbẹ kuro niwaju awọn ọmọ Israeli, titi
awa fi là a kọja, ni àiya wọn já, bẹ̀li ẹmi
kò sí ninu wọn mọ́, nitori awọn ọmọ
Israeli.
2 Nigbana li OLUWA wi fun Joṣua pe,
Fi okuta ṣe abẹ ki iwọ ki o si tun kọ awọn
ọmọ Israeli nilà lẹ̀keji.
3 Joṣua si ṣe abẹ okuta, o si kọ awọn
ọmọ Israeli nilà, ni Gibeati-haaralotu.
4 Idí rẹ̀ li eyi ti Joṣua fi kọ wọn nilà:
gbogbo awọn enia ti o ti Egipti jade wá, ti
o ṣe ọkọnrin, ani gbogbo awọn ọmọ-ogun,
nwọn kú li aginjù, li ọ̀na, lẹhin igbati
nwọn jade kuro ni Egipti.
5 Nitori gbogbo awọn enia ti o jade ti
ibẹ̀ wá, a kọ wọn nilà: ṣugbọn gbogbo
awọn enia ti a bi li aginjù li ọ̀na, bi nwọn
ti jade kuro ni Egipti, awọn ni a kò kọnilà.
6 Nitoriti awọn ọmọ Israeli rìn li ogoji
ọdún li aginjù, titi gbogbo iran na, ani
awọn ologun, ti o jade ti Egipti wá fi run,
nitoriti nwọn kò gbà ohùn OLUWA gbọ́:
awọn ti OLUWA bura fun pe, on ki yio jẹ
ki wọn ri ilẹ na, ti OLUWA bura fun awọn
baba wọn lati fi fun wa, ilẹ ti nṣàn fun
warà ati fun oyin.
7 Ati awọn ọmọ wọn, ti o gbé dide ni
ipò wọn, awọn ni Joṣua kọnilà: nitoriti
nwọn wà li alaikọlà, nitoriti a kò kọ wọn
nilà li ọ̀na.
8 O si ṣe, nigbati nwọn kọ gbogbo awọn
enia na nilà tán, nwọn joko ni ipò wọn ni
ibudó, titi ara wọn fi dá.
9 OLUWA si wi fun Joṣua pe, Li oni ni
mo yi ẹ̀gan Egipti kuro lori nyin. Nito-
rina li a ṣe npè orukọ ibẹ̀ ni Gilgali titi o
fi di oni yi.
10 Awọn ọmọ Israeli si dó ni Gilgali;
nwọn si ṣe ajọ irekọja li ọjọ́ kẹrinla oṣù li
ọjọ́ alẹ, ni pẹtẹlẹ̀ Jeriko.

Digitized by Google

11 Nwọn si jẹ ọkà gbigbẹ ilẹ na ni ijọ́
keji lẹhin irekọja, àkara alaiwu, ọkà didin
li ọjọ̀ na gan.
12 Manna si dá ni ijọ́ keji lẹhin igbati
nwọn ti jẹ ọkà gbigbẹ ilẹ na; awọn ọmọ
Israeli kò si ri manna mọ́; ṣugbọn nwọn jẹ
eso ilẹ Kenaani li ọdún na.
13 O si ṣe, nigbati Joṣua wà leti Jeriko,
o gbé oju rẹ̀ soke o si wò, si kiyesi i, ọkọn-
rin kan duro niwaju rẹ̀ pẹlu idà fifayọ li
ọwọ́ rẹ̀: Joṣua si tọ̀ ọ lọ, o si wi fun u pe,
Ti wa ni iwọ nṣe, tabi ti ọtá wa?
14 O si wipe, Bẹ̃kọ; ṣugbọn bi olori
ogun OLUWA ni mo wá si nisisiyi. Joṣua
si wolẹ niwaju rẹ̀, o si foribalẹ, o si wi fun
pe, Kili oluwa mi ni isọ fun iranṣẹ rẹ̀?
15 Olori-ogun OLUWA si wi fun Joṣua
pe, Bọ́ salubata rẹ kuro li ẹsẹ̀ rẹ; nitoripe
ibi ti iwọ gbé duro nì ibi mimọ́ ni. Joṣua
si ṣe bẹ̃.

ORI 6.

NJẸ a há Jeriko mọ́ gága nitori awọn
ọmọ Israeli: ẹnikẹni kò jade, ẹni-
kẹni kò si wọle.)
2 OLUWA si wi fun Joṣua pe, Wò o, mo
ti fi Jeriko lé ọ lọwọ, ati ọba rẹ̀, ati awọn
alagbara akọni.
3 Ẹnyin o si ká ilu na mọ́, gbogbo ẹnyin
ologun, ẹnyin o si yi ilu na ká lẹ̃kan. Bayi
ni iwọ o ṣe ni ijọ́ mẹfa.
4 Alufa meje yio gbé ipè jubeli meje ni-
waju apoti na: ni ijọ́ keje ẹnyin o si yi ilu
na ká lẹ̃meje, awọn alufa yio si fọn ipè
wọnni.
5 Yio si ṣe, nigbati nwọn ba fọn ipè
jubeli kikan, nigbati ẹnyin ba si gbọ́ iró
ipè na, gbogbo awọn enia yio si hó kũ; odi
ilu na yio si wó lulẹ bẹrẹ, awọn enia yio si
gòke lọ tàra, olukuluku niwaju rẹ̀.
6 Joṣua ọmọ Nuni si pè awọn alufa, o si
wi fun wọn pe, Ẹ gbé apoti majẹmu na, ki
alufa meje ki o gbé ipè jubeli meje nì ni-
waju apoti OLUWA.
7 O si wi fun awọn enia pe, Ẹ kọja, ki ẹ
si yi ilu na ká, ki awọn ti o hamọra ki o
si kọja niwaju apoti OLUWA.
8 O si ṣe, nigbati Joṣua wi fun awọn enia
tán, awọn alufa meje ti o gbé ipè jubeli
meje, kọja niwaju OLUWA, nwọn si fọn ipè
wọnni: apoti majẹmu OLUWA si tẹle wọn.
9 Awọn ti o hamọra si lọ niwaju awọn
alufa, ti nfọn ipè, ogun-ẹhin si ntọ̀ apoti
lẹhin, awọn alufa nlọ nwọn si nfọn ipè.
10 Joṣua si paṣẹ fun awọn enia wipe, Ẹ
kò gbọdọ hó, bẹ̃li ẹ kò gbọdọ pariwo, bẹ̃li
ọ̀rọ kan kò gbọdọ jade li ẹnu nyin, titi ọjọ́
ti emi o wi fun nyin pe, ẹ hó; nigbana li
ẹnyin o hó.
11 Bẹ̃li o mu ki apoti OLUWA ki o yi ilu
na ká, o yi i ká lẹ̃kan: nwọn si lọ si ibudó,
nwọn si wọ̀ ni ibudó.
12 Joṣua si dide ni kùtukutu owurọ̀,
awọn alufa si gbé apoti OLUWA.
13 Awọn alufa meje ti o gbé ipè jubeli
meje niwaju apoti OLUWA nlọ titi, nwọn si
nfọn ipè wọnni: awọn ti o hamọra-ogun
nlọ niwaju wọn; ogun-ẹhin si ntọ̀ apoti
OLUWA lẹhin, awọn alufa si nfọn ipè bi
nwọn ti nlọ.
14 Li ọjọ́ keji nwọn yi ilu na ká lẹ̃kan,
nwọn si pada si ibudó; bẹ̃ni nwọn ṣe ni
ijọ́ mẹfa.
15 O si ṣe ni ijọ́ keje, nwọn dide ni kù-
tukutu li afẹmọjumọ́, nwọn si yi ilu na ká
gẹgẹ bi ti iṣaju lẹ̃meje: li ọjọ́ na nikanṣoṣo
ni nwọn yi ilu na ká lẹ̃meje.
16 O si ṣe ni ìgba keje, nigbati awọn
alufa fọn ipè, ni Joṣua wi fun awọn enia pe,
Ẹ hó; nitori OLUWA ti fun nyin ni ilu na.
17 Ilu na yio si jẹ́ ìyasọtọ si OLUWA, on
ati gbogbo ohun ti mbẹ ninu rẹ̀: kìki Ra-
habu panṣaga ni yio là, on ati gbogbo awọn
ti mbẹ ni ile pẹlu rẹ̀, nitoriti o pa awọn
onṣẹ ti a rán mọ́.
18 Ati ẹnyin, bi o ti wù ki o ri, ẹ pa ara
nyin mọ́ kuro ninu ohun ìyasọtọ, ki ẹ má
ba yà a sọ̀tọ tán ki ẹ si mú ninu ohun ìya-
sọtọ na; ẹnyin a si sọ ibudó Israeli di ifibu,
ẹnyin a si mu iyọnu bá a.
19 Ṣugbọn gbogbo fadakà, ati wurà, ati
ohunèlo idẹ ati ti irin, mimọ́ ni fun OLUWA:
nwọn o wá sinu iṣura OLUWA.
20 Bẹ̃li awọn enia na hó, nigbati awọn
alufa fọn ipè: o si ṣe, nigbati awọn enia
gbọ́ iró ipè, ti awọn enia si hó kũ, odi na
wólulẹ bẹrẹ, bẹ̃li awọn enia wọ̀ inu ilu na
lọ, olukuluku tàra niwaju rẹ̀, nwọn si kó
ilu na.
21 Nwọn si fi oju idà pa gbogbo ohun ti
o wà ni ilu na run, ati ọkọnrin ati obirin,
ati ewe ati àgba, ati akọmalu, ati agutan,
ati kẹtẹkẹtẹ.
22 Ṣugbọn Joṣua sọ fun awọn ọkọnrin
meji ti o ti ṣe amí ilẹ na pe, Ẹ lọ si ile pan-
ṣaga nì, ki ẹ si mú obirin na jade nibẹ̀,
ati ohun gbogbo ti o ní, gẹgẹ bi ẹnyin ti
bura fun u.
23 Awọn ọmọkọnrin ti o ṣamí si wọle,
nwọn si mú Rahabu jade, ati baba rẹ̀, ati
iya rẹ̀, ati awọn arakọnrin rẹ̀, ati ohun
gbogbo ti o ní, nwọn si mú gbogbo awọn

Digitized by Google

ibatan rẹ̀ jade; nwọn si fi wọn si ẹhin ibu-
dó Israeli.
24 Nwọn si fi iná kun ilu na ati ohun
gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀; kìki fadakà, ati
wurà, ati ohunèlo idẹ ati irin, ni nwọn fi
sinu işura ile OLUWA.
25 Joşua si gbà Rahabu panşaga là, ati
ara ile baba rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o ní; o
si joko lãrin Israeli titi di oni-oloni; nito-
riti o pa awọn onşẹ mọ́ ti Joşua rán lọ şamí
Jeriko.
26 Joşua si gégun li akokò na wipe,
Egún ni fun ọkọnrin na niwaju OLUWA ti
yio dide, ti yio si kọ ilu Jeriko yi: pẹlu
ikú akọ́bi rẹ̀ ni yio fi pilẹ rẹ̀, ati pẹlu ikú
abikẹhin rẹ̀ ni yio fi gbé ilẹkun ibode rẹ̀ ró.
27 Bẽni OLUWA wà pẹlu Joşua; okikí
rẹ̀ si kàn ká gbogbo ilẹ na.

## ORI 7.

ŞUGBỌN awọn ọmọ Israeli dẹşẹ kan niti
ohun ìyasọtọ: nitoriti Akani, ọmọ
Karmi, ọmọ Sabdi, ọmọ Sera, ẹ̀ya Juda,
mú ninu ohun ìyasọtọ: ibinu OLUWA si
rú si awọn ọmọ Israeli.
2 Joşua si rán enia lati Jeriko lọ si Ai,
ti mbẹ lẹba Beti-afeni, ni ìla-õrùn Beti-eli,
o si wi fun wọn pe, Ẹ gòke lọ ki ẹ si şamí
ilẹ na. Awọn enia na gòke lọ nwọn si şa-
mí Ai.
3 Nwọn si pada tọ̀ Joşua wá, nwọn si
wi fun u pe, Máşe jẹ ki gbogbo enia ki o
gòke lọ; şugbọn jẹ ki ìwọn ẹgba tabi ẹgbẹ-
dogun enia ki o gòke lọ ki nwọn si kọlù
Ai; máşe jẹ ki gbogbo enia lọ şíşẹ nibẹ̀;
nitori diẹ ni nwọn.
4 Bẽni ìwọn ẹgbẹdogun enia gòke lọ si-
bẹ̀: nwọn si sá niwaju awọn enia Ai.
5 Awọn enia Ai pa enia mẹrindilogoji
ninu wọn: nwọn si lepa wọn lati ẹnubode
titi dé Şebarimu, nwọn si pa wọn bi nwọn
ti nsọkalẹ: àiya awọn enia na já, o si di
omi.
6 Joşua si fà aşọ rẹ̀ ya, o si dojubolẹ
niwaju apoti OLUWA titi di aşalẹ, on ati
awọn àgba Israeli; nwọn si bù ekuru si
ori wọn.
7 Joşua si wipe, Yẽ, Oluwa ỌLỌRUN,
nitori kini iwọ fi mú awọn enia yi kọja
Jordani, lati fi wa lé ọwọ́ awọn Amori, lati
pa wa run? awa iba mọ̀ ki a joko ni ìha
keji ọhún Jordani!
8 A, Oluwa, kili emi o wi, nigbati
Israeli pa ẹhin wọn dà niwaju awọn ọtá
wọn!
9 Nitoriti awọn ara Kenaani ati gbogbo
awọn ara ilẹ na yio gbọ́, nwọn o si yi wa
ká, nwọn o si ke orukọ wa kuro li aiye:
kini iwọ o ha şe fun orukọ nla rẹ?
10 OLUWA si wi fun Joşua pe, Dide;
ẽşe ti iwọ fi doju rẹ bolẹ bayi?
11 Israeli ti dẹşẹ, nwọn si ti bà majẹmu
mi jẹ́ ti mo palaşẹ fun wọn: ani nwọn ti
mú ninu ohun ìyasọtọ nì; nwọn si jale,
nwọn si şe agabagebe pẹlu, ani nwọn si fi i
sinu ẹrù wọn.
12 Nitorina ni awọn ọmọ Israeli kò şe
le duro niwaju awọn ọtá wọn, nwọn pẹhin-
da niwaju awọn ọtá wọn, nitoriti nwọn
di ẹni ifibu: emi ki yio wà pẹlu nyin mọ́,
bikoşepe ẹnyin pa ohun ìyasọtọ run kuro
lãrin nyin.
13 Dide, yà awọn enia na simimọ́, ki o
si wipe, Ẹ yà ara nyin simimọ́ fun ọla:
nitori bayi li OLUWA, Ọlọrun Israeli wipe;
Ohun ìyasọtọ kan mbẹ ninu rẹ, iwọ
Israeli: iwọ ki yio le duro niwaju awọn
ọtá rẹ, titi ẹnyin o fi mú ohun ìyasọtọ na
kuro ninu nyin.
14 Nitorina li owurọ̀ a o mú nyin wá
gẹgẹ bi ẹ̀ya nyin: yio si şe, ẹ̀ya ti OLUWA
ba mú yio wá gẹgẹ ni idile idile: ati idile
ti OLUWA ba mú yio wá li agbagbole; ati
agbole ti OLUWA ba mú yio wá li ọkọnrin
kọkan.
15 Yio si şe, ẹniti a ba mú pẹlu ohun
ìyasọtọ na, a o fi iná sun u, on ati ohun
gbogbo ti o ní: nitoriti o rú ofin OLUWA,
ati nitoriti o si hù ìwakiwa ni Israeli.
16 Bẽni Joşua dide ni kùtukutu owurọ̀,
o si mú Israeli wá gẹgẹ bi ẹ̀ya wọn; a si
mú ẹ̀ya Juda:
17 O si mú idile Juda wá; a si mu idile
Sera: o si mú idile Sera wá li ọkọnrin
kọkan; a si mú Sabdi:
18 O si mú ará ile rẹ̀ li ọkọnrin kọkan;
a si mú Akani ọmọ Karmi, ọmọ Sabdi,
ọmọ Sera ninu, ẹ̀ya Juda.
19 Joşua si wi fun Akani pe, Ọmọ mi,
mo bẹ̀ ọ, fi ogo fun OLUWA, Ọlọrun Israeli,
ki o si jẹwọ fun u; ki o si sọ fun mi
nisisiyi, ohun ti iwọ şe; má şe pa a mọ́
fun mi.
20 Akani si da Joşua lohùn, o si wipe,
Nitõtọ ni mo şẹ̀ si OLUWA, Ọlọrun Israeli,
bayi bayi ni mo şe:
21 Nigbati mo ri ẹ̀wu Babeli kan dara-
dara ninu ikogun, ati igba şekeli fadakà,
ati dindi wurà kan oloşuwọn ãdọta şekeli,
mo şojukokoro wọn, mo si mú wọn; sawò
o, a fi wọn pamọ́ ni ilẹ lãrin agọ́ mi, ati
fadakà na labẹ rẹ̀.

Digitized by Google

22 Joṣua si rán onṣẹ, nwọn si sare wọ̀
inu agọ́ na; si kiyesi i, a fi i pamọ́ ninu
agọ́ rẹ̀, ati fadakà labẹ rẹ̀.
23 Nwọn si mú wọn jade lãrin agọ́ na,
nwọn si mú wọn wá sọdọ Joṣua, ati sọdọ
gbogbo awọn ọmọ Israeli, nwọn si fi wọn
lelẹ niwaju OLUWA.
24 Joṣua, ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀, si
mú Akani ọmọ Sera, ati fadakà na, ati
ẹ̀wu na, ati dindi wurà na, ati awọn ọmọ
rẹ̀ ọkọnrin, ati awọn ọmọ rẹ̀ obirin, ati
akọmalu rẹ̀, ati kẹtẹkẹtẹ rẹ̀, ati agutan rẹ̀,
ati agọ́ rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o ní; nwọn
si mú wọn lọ si ibi afonifoji Akoru.
25 Joṣua si wipe, Ẽṣe ti iwọ fi yọ wa
lẹnu? OLUWA yio yọ iwọ na lẹnu li oni
yi. Gbogbo Israeli si sọ ọ li okuta pa;
nwọn si dánasun wọn, nwọn sọ wọn li
okuta.
26 Nwọn si kó òkiti okuta nla kan lé e
lori titi di oni-oloni; OLUWA si yipada
kuro ninu imuna ibinu rẹ̀. Nitorina li a
ṣe npè orukọ ibẹ̀ li Afonifoji Akoru, titi di
oni-oloni.

## ORI 8.

OLUWA si wi fun Joṣua pe, Máṣe bẹ̀ru,
bẹ̃ni ki àiya ki o má ṣe fò ọ: mú
gbogbo awọn ọmọ-ogun pẹlu rẹ ki iwọ ki o
si dide, ki o si gòke lọ si Ai: kiyesi i, emi
ti fi ọba Ai, ati awọn enia rẹ̀, ati ilunla rẹ̀,
ati ilẹ rẹ̀ lé ọ lọwọ:
2 Iwọ o si ṣe si Ai ati si ọba rẹ̀ gẹgẹ bi
iwọ ti ṣe si Jeriko ati si ọba rẹ̀: kìki ikogun
rẹ̀, ati ohunọ̀sin rẹ̀, li ẹnyin o mú ni iko-
gun fun ara nyin: rán enia lọ iba lẹhin
ilu na.
3 Joṣua si dide, ati gbogbo awọn ọmọ-
ogun, lati gòke lọ si Ai: Joṣua si yàn ẹgbã
mẹdogun, alagbara akọni, o si rán wọn lọ
li oru.
4 O si paṣẹ fun wọn pe, Wò o, ẹnyin o
ba tì ilu na, ani lẹhin ilu na: ẹ má ṣe
jìna pupọ̀ si ilu na, ṣugbọn ki gbogbo nyin
ki o murasilẹ.
5 Ati emi, ati gbogbo awọn enia ti o wà
pẹlu mi, yio sunmọ ilu na: yio si ṣe,
nigbati nwọn ba jade si wa, gẹgẹ bi ti ìgba
iṣaju, awa o si sá niwaju wọn;
6 Nitoriti nwọn o jade si wa, titi awa o
fi fà wọn jade kuro ni ilu; nitoriti nwọn
o wipe, Nwọn sá niwaju wa, gẹgẹ bi ti
ìgba iṣaju; nitorina li awa o sá niwaju
wọn:
7 Nigbana li ẹnyin o dide ni buba, ẹnyin
o si gbà ilu na: nitoriti OLUWA Ọlọrun
nyin yio fi i lé nyin lọwọ.
8 Yio si ṣe, nigbati ẹnyin ba gbà ilu na
tán, ki ẹnyin ki o si tinabọ ilu na; gẹgẹ bi
aṣẹ OLUWA ni ki ẹnyin ki o ṣe: wò o, mo
ti fi aṣẹ fun nyin na.
9 Nitorina ni Joṣua ṣe rán wọn lọ: nwọn
lọ iba, nwọn si joko li agbedemeji Beteli
ati Ai, ni ìha ìwọ-õrùn Ai: ṣugbọn Joṣua
dó li oru na lãrin awọn enia.
10 Joṣua si dide ni kùtukutu owurọ̀, o
si kà awọn enia, o si gòke lọ si Ai, on, ati
awọn àgba Israeli niwaju awọn enia.
11 Ati gbogbo awọn enia, ani awọn ọmọ-
ogun ti mbẹ pẹlu rẹ̀, nwọn gòke lọ, nwọn
si sunmọtosi, nwọn si wá siwaju ilu na,
nwọn si dó ni ìha ariwa Ai; afonifoji si
mbẹ li agbedemeji wọn ati Ai.
12 O si mú to bi ẹgbẹdọgbọ̀n enia, o si
fi wọn si ibuba li agbedemeji Beteli ati Ai,
ni ìha ìwọ-õrùn ilu na.
13 Nwọn si yàn awọn enia si ipò, ani
gbogbo ogun ti mbẹ ni ìha ariwa ilu na,
ati awọn enia ti o ba ni ìha ìwọ-õrùn ilu
na; Joṣua si lọ li oru na sãrin afonifoji
na.
14 O si ṣe, nigbati ọba Ai ri i, nwọn
yára nwọn si dide ni kùtukutu, awọn
ọkọnrin ilu na si jade si Israeli lati jagun,
ati on ati gbogbo awọn enia rẹ̀, niwaju
pẹtẹlẹ̀, ibi ti a ti yàn tẹlẹ; ṣugbọn on kò
mọ̀ pe awọn ti o ba dè e mbẹ lẹhin ilu.
15 Joṣua ati gbogbo awọn Israeli si ṣe bi
ẹniti a lé niwaju wọn, nwọn si sá gbà ọ̀na
aginjù.
16 A si pe gbogbo enia ti mbẹ ni Ai jọ
lati lepa wọn: nwọn si lepa Joṣua, a si fà
wọn jade kuro ni ilu.
17 Kò si kù ọkọnrin kan ni Ai tabi Beti-
eli, ti kò jade tọ̀ Israeli: nwọn si fi ilunla
silẹ ni ṣíṣí nwọn si lepa Israeli.
18 OLUWA si wi fun Joṣua pe, Nà ọ̀kọ
ti mbẹ li ọwọ́ rẹ nì si Ai; nitoriti emi o fi
i lé ọ lọwọ. Joṣua si nà ọ̀kọ na ti o ní li
ọwọ́ rẹ̀ si ilu na.
19 Awọn ti o ba si dide kánkan kuro ni
ipò wọn, bi o si ti nàwọ́ rẹ̀, nwọn sare,
nwọn si wọ̀ ilu na lọ, nwọn si gbà a; nwọn
si yára tinabọ ilu na.
20 Nigbati awọn ọkọnrin Ai bojuwò-ẹhin
wọn, kiyesi i, nwọn ri ẽfi ilu na ngòke lọ
si ọrun, nwọn kò si lí agbara lati gbà ihin
tabi ọhún sálọ: awọn enia ti o sá si aginjù
si yipada si awọn ti nlepa.
21 Nigbati Joṣua ati gbogbo Israeli ri bi
awọn ti o ba ti gbà ilu, ti ẽfi ilu na si

Digitized by Google

gòke, nwọn si yipada, nwọn si pa awọn
ọkọnrin Ai.
22 Awọn ti ara keji si yọ si wọn lati ilu
na wá; bẽni nwọn wà li agbedemeji Israeli,
awọn miran li apa ihin, awọn miran li apa
ọhún: nwọn si pa wọn, bẽni nwọn kò
si jẹ ki ọkan ki o kù tabi ki o sálọ ninu
wọn.
23 Nwọn si mú ọba Ai lãye, nwọn si mú
u wá sọdọ Joṣua.
24 O si ṣe, nigbati Israeli pari pipa
gbogbo awọn ara ilu Ai ni igbẹ́, ati ni
aginjù ni ibi ti nwọn lé wọn si, ti gbogbo
wọn si ti oju idà ṣubu, titi a fi run wọn, ni
gbogbo awọn ọmọ Israeli pada si Ai, nwọn
si fi oju idà kọlù u.
25 O si ṣe, gbogbo awọn ti o ṣubu ni
ijọ́ na, ati ọkọnrin ati obirin, jẹ́ ẹgba mẹfa,
ani gbogbo ọkọnrin Ai.
26 Nitoriti Joṣua kò fà ọwọ́ rẹ̀ ti o fi nà
ọ̀kọ sẹhin, titi o fi run gbogbo awọn ara
ilu Ai tútu.
27 Kìki ohunọ̀sin ati ikogun ilu na ni
Israeli jẹ fun ara wọn, gẹgẹ bi ọ̀rọ OLUWA
ti o palaṣẹ fun Joṣua.
28 Joṣua si kun Ai, o sọ ọ di òkiti lailai,
ani ahoro titi di oni-oloni.
29 Ọba Ai li o si sorọ̀ lori igi titi di
aṣalẹ: bi õrùn si ti wọ̀, Joṣua paṣẹ ki a sọ
okú rẹ̀ kuro lori igi kalẹ, ki a si wọ́ ọ jù si
atiwọ̀ ibode ilu na, ki a si kó òkiti nla
okuta lé e lori, ti mbẹ nibẹ̀ titi di oni-
oloni.
30 Nigbana ni Joṣua tẹ́ pẹpẹ kan fun
OLUWA, Ọlọrun Israeli, li òke Ebali,
31 Gẹgẹ bi Mose iranṣẹ OLUWA ti paṣẹ
fun awọn ọmọ Israeli, gẹgẹ bi a ti kọ ọ
ninu iwé ofin Mose, pẹpẹ odidi okuta, lara
eyiti ẹnikan kò fi irin kan: nwọn si ru ẹbọ
sisun lori rẹ̀ si OLUWA, nwọn si ru ẹbọ
alafia.
32 O si kọ apẹrẹ ofin Mose sara okuta na,
ti o kọ niwaju awọn ọmọ Israeli.
33 Ati gbogbo Israeli, ati awọn àgba
wọn, ati awọn olori, ati awọn onidajọ wọn,
duro li apa ihin ati li apa ọhún apoti ẹrí
niwaju awọn alufa awọn ọmọ Lefi, ti o rù
apoti majẹmu OLUWA, ati alejò ati ibilẹ;
àbọ wọn kọjusi òke Gerisimu; ati àbọ wọn
kọjusi òke Ebali, gẹgẹ bi Mose iranṣẹ
OLUWA ti paṣẹ rí, pe ki nwọn ki o sure fun
awọn enia Israeli.
34 Lẹhin eyi o si kà gbogbo ọ̀rọ ofin,
ibukún ati egún, gẹgẹ bi gbogbo eyiti a kọ
ninu iwé ofin.
35 Kò kù ọ̀rọ kan ninu gbogbo eyiti
Mose palaṣẹ, ti Joṣua kò kà niwaju gbogbo
ijọ Israeli, ati awọn obirin, ati awọn ọmọ
wẹrẹ, ati awọn alejò ti nrìn lãrin wọn.

## ORI 9.

O SI ṣe, nigbati gbogbo awọn ọba ti mbẹ
li apa ihin Jordani, li ori òke, ati li
afonifoji, ati ni gbogbo àgbegbe okun nla ti
o kọjusi Lebanoni, awọn Hitti, ati awọn
Amori, awọn Kenaani, awọn Perissi, awọn
Hifi, ati awọn Jebusi, gbọ́ ọ;
2 Nwọn si kó ara wọn jọ, lati fi ìmọ kan
bá Joṣua ati Israeli jà.
3 Ṣugbọn nigbati awọn ara Gibeoni gbọ́
ohun ti Joṣua ṣe si Jeriko ati si Ai,
4 Nwọn ṣe ẹ̀tan, nwọn si lọ nwọn si ṣe
bi ẹnipe onṣẹ ni nwọn, nwọn si mú ogbolo-
gbo àpo kà ori kẹtẹkẹtẹ wọn, ati ìgo-awọ
ọti-waini ti lailai, ti o ya, ti a si dì;
5 Ati bàta gbigbo ati lilẹ̀ li ẹsẹ̀ wọn, ati
ẹ̀wu gbigbo li ara wọn; ati gbogbo àkara
èse wọn o gbẹ o si hùkasi.
6 Nwọn si tọ̀ Joṣua lọ ni ibudó ni Gilgali,
nwọn si wi fun u, ati fun awọn ọkọnrin
Israeli pe, Ilu òkere li awa ti wá; njẹ
nitorina ẹ bá wa dá majẹmu.
7 Awọn ọkọnrin Israeli si wi fun awọn
Hifi pe, Bọya ẹnyin ngbé ãrin wa; awa o
ti ṣe bá nyin dá majẹmu?
8 Nwọn si wi fun Joṣua pe, Iranṣẹ rẹ li
awa iṣe. Joṣua si wi fun wọn pe, Tali
ẹnyin? nibo li ẹnyin si ti wá?
9 Nwọn si wi fun u pe, Ni ilu òkere
rére li awọn iranṣẹ rẹ ti wá, nitori orukọ
OLUWA Ọlọrun rẹ: nitoriti awa ti gbọ́
okikí rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o ṣe ni Egipti,
10 Ati ohun gbogbo ti o ṣe si awọn ọba
awọn Amori meji, ti mbẹ ni òke Jordani,
si Sihoni ọba Heṣboni, ati si Ogu ọba
Baṣani, ti mbẹ ni Aṣtarotu.
11 Awọn àgba wa ati gbogbo awọn ara
ilu wa sọ fun wa pe, Ẹ mú onjẹ li ọwọ́ nyin
fun àjo na, ki ẹ si lọ ipade wọn, ki ẹ si wi
fun wọn pe, Iranṣẹ nyin li awa iṣe: njẹ
nitorina, ẹ bá wa dá majẹmu.
12 Akara wa yi ni gbigbona li a mú u
fun èse wa, lati ile wa wá, li ọjọ́ ti a jade
lati tọ̀ nyin wá; ṣugbọn nisisiyi, kiyesi i,
o gbẹ, o si hùkasi:
13 Igo-awọ waini wọnyi, ti awa kún,
titun ni nwọn; kiyesi i, nwọn fàya: ati
ẹ̀wu wa wọnyi ati bàta wa di gbigbo nitori
ọ̀na ti o jìn jù.
14 Awọn ọkọnrin si gbà ninu onjẹ wọn,
nwọn kò si bère li ẹnu OLUWA.
15 Joṣua si bá wọn ṣọrẹ, o si bá wọn dá

Digitized by Google

majẹmu lati da wọn si: awọn olori ijọ enia
fi OLUWA Ọlọrun Israeli bura fun wọn.
16 O si ṣe li opin ijọ́ mẹta, lẹhin ìgbati
nwọn bá wọn dá majẹmu, ni nwọn gbọ́ pe
aladugbo wọn ni nwọn, ati pe lãrin wọn ni
nwọn gbé wà.
17 Awọn ọmọ Israeli si dide, nwọn si dé
ilu wọn ni ijọ́ kẹta. Njẹ ilu wọn ni Gibeoni,
ati Kefira, ati Beerotu, ati Kiriati-jearimu.
18 Awọn ọmọ Israeli kò pa wọn, nitoriti
awọn olori ijọ awọn enia ti fi OLUWA,
Ọlọrun Israeli, bura fun wọn. Gbogbo
ijọ awọn enia si kùn si awọn olori.
19 Ṣugbọn gbogbo awọn olori wi fun
gbogbo ijọ pe, Awa ti fi OLUWA, Ọlọrun
Israeli, bura fun wọn: njẹ nitorina awa kò
le fọwọkàn wọn.
20 Eyi li awa o ṣe si wọn, ani awa o da
wọn si, ki ibinu ki o má ba wà lori wa,
nitori ibura ti a bura fun wọn.
21 Awọn olori si wi fun wọn pe, Ẹ da
wọn si: nwọn si di aṣẹ́gi ati apọnmi fun
gbogbo ijọ; gẹgẹ bi awọn olori ti sọ fun
wọn.
22 Joṣua si pè wọn, o si wi fun wọn pe,
Ẽṣe ti ẹnyin fi tàn wa wipe, Awa jìna rére
si nyin; nigbati o jẹ́ pe lãrin wa li ẹnyin
ngbé?
23 Njẹ nitorina ẹnyin di ẹni egún, ẹrú li
ẹnyin o si ma jẹ́ titi, ati aṣẹ́gi ati apọnmi
fun ile Ọlọrun mi.
24 Nwọn si da Joṣua lohùn wipe,
Nitoriti a sọ fun awọn iranṣẹ rẹ dajudaju,
bi OLUWA Ọlọrun rẹ ti paṣẹ fun Mose
iranṣẹ rẹ̀, lati fun nyin ni gbogbo ilẹ na, ati
lati pa gbogbo awọn ara ilẹ na run kuro
niwaju nyin; nitorina awa bẹ̀ru nyin gidi-
gidi nitori ẹmi wa, a si ṣe nkan yi.
25 Njẹ nisisiyi, kiyesi i, li ọwọ́ rẹ li awa
wà: bi o ti dara si ati bi o ti tọ́ si li oju rẹ
lati ṣe wa, ni ki iwọ ki o ṣe.
26 Bẹ̃li o si ṣe wọn, o si gbà wọn li ọwọ́
awọn ọmọ Israeli, nwọn kò si pa wọn.
27 Joṣua si ṣe wọn li aṣẹ́gi ati apọnmi
fun ijọ, ati fun pẹpẹ OLUWA li ọjọ́ na, ani
titi di oni-oloni, ni ibi ti o ba yàn.

## ORI 10.

O SI ṣe, nigbati Adoni-sedeki ọba Jerusa-
lemu gbọ́ pe Joṣua ti kó Ai, ti o si pa
a run patapata; bi o ti ṣe si Jeriko ati si
ọba rẹ̀, bẹ̃li o si ṣe si Ai ati si ọba rẹ̀; ati
bi awọn ara Gibeoni ti bá Israeli ṣọrẹ, ti
nwọn si ngbé ãrin wọn;
2 Nwọn bẹ̀ru pipọ̀, nitoriti Gibeoni ṣe
ilu nla, bi ọkan ninu awọn ilu ọba, ati
nitoriti o tobi jù Ai lọ, ati gbogbo ọkọnrin
inu rẹ̀ jẹ́ alagbara.
3 Nitorina Adoni-sedeki ọba Jerusalemu
ranṣẹ si Hohamu ọba Hebroni, ati si
Piramu ọba Jarmutu, ati si Jafia ọba
Lakiṣi, ati si Debiri ọba Egloni, wipe,
4 Ẹ gòke tọ̀ mi wá, ki ẹ si ràn mi lọwọ,
ki awa ki o le kọlù Gibeoni: nitoriti o bá
Joṣua ati awọn ọmọ Israeli ṣọrẹ.
5 Awọn ọba Amori mararun, ọba Jerusa-
lemu, ọba Hebroni, ọba Jarmutu, ọba
Lakiṣi, ati ọba Egloni, kó ara wọn jọ,
nwọn si gòke, awọn ati gbogbo ogun wọn,
nwọn si dótì Gibeoni, nwọn si fi ìja fun u.
6 Awọn ọkọnrin Gibeoni si ranṣẹ si
Joṣua ni ibudó ni Gilgali, wipe, Máṣe fà
ọwọ́ rẹ sẹhin kuro lọdọ awọn iranṣẹ rẹ;
gòke tọ̀ wa wá kánkán, ki o si gbà wa, ki o
si ràn wa lọwọ: nitoriti gbogbo awọn ọba
Amori ti ngbé ori òke kójọ pọ̀ si wa.
7 Bẹ̃ni Joṣua gòke lati Gilgali lọ, on ati
gbogbo awọn ọmọ-ogun pẹlu rẹ̀, ati gbogbo
awọn alagbara akọni.
8 OLUWA si wi fun Joṣua pe, Máṣe
bẹ̀ru wọn: nitoriti mo ti fi wọn lé ọ lọwọ;
ki yio sí ọkọnrin kan ninu wọn ti yio le
duro niwaju rẹ.
9 Joṣua si yọ si wọn lojijì; o si gòke
lati Gilgali lọ ni gbogbo oru na.
10 OLUWA si fọ́ wọn niwaju Israeli, o si
pa wọn ni ipakupa ni Gibeoni, o si lepa
wọn li ọ̀na òke Beti-horoni, o si pa wọn dé
Aseka, ati dé Makkeda.
11 O si ṣe, bi nwọn ti nsá niwaju
Israeli, ti nwọn dé gẹrẹgẹrẹ Beti-horoni,
OLUWA rọ̀ yinyin nla si wọn lati ọrun wá
titi dé Aseka, nwọn si kú: awọn ti o ti
ipa yinyin kú, o pọ̀ju awọn ti awọn ọmọ
Israeli fi idà pa lọ.
12 Nigbana ni Joṣua wi fun OLUWA li
ọjọ́ ti OLUWA fi awọn Amori fun awọn ọmọ
Israeli, o si wi li oju Israeli pe, Iwọ, Õrùn,
duro jẹ lori Gibeoni; ati Iwọ, Oṣupa, li
afonifoji Aijaloni.
13 Õrùn si duro jẹ, oṣupa si duro, titi
awọn enia fi gbẹsan lara awọn ọtá wọn. A
kò ha kọ eyina sinu iwé Jaṣeri? Bẹ̃li
õrùn duro li agbedemeji ọrun, kò si yára
lati wọ̀ niwọn ọjọ́ kan tọtọ.
14 Kò sí ọjọ́ ti o dabi rẹ̀ ṣaju rẹ̀ tabi
lẹhin rẹ̀, ti OLUWA gbọ́ ohùn enia: nito-
riti OLUWA jà fun Israeli.
15 Joṣua si pada, ati gbogbo Israeli
pẹlu rẹ̀, si ibudó ni Gilgali.
16 Ṣugbọn awọn ọba marun nì sá, nwọn
si fara wọn pamọ́ ni ihò kan ni Makkeda.



Digitized by Google

17 A si sọ fun Joṣua pe, A ri awọn ọba
marun ni ifarapamọ́ ni ihò ni Makkeda.
18 Joṣua si wipe, Ẹ yí okuta nla di ẹnu
ihò na, ki ẹ si yàn enia sibẹ̀ lati ṣọ́ wọn:
19 Ṣugbọn ẹnyin, ẹ máṣe duro, ẹ lepa
awọn ọtá nyin, ki ẹ si kọlù wọn lẹhin; ẹ
máṣe jẹ ki nwọn ki o wọ̀ ilu wọn lọ:
nitoriti OLUWA Ọlọrun nyin ti fi wọn lé
nyin lọwọ.
20 O si ṣe, nigbati Joṣua ati awọn ọmọ
Israeli pa wọn ni ipakupa tán, titi a fi run
wọn, ti awọn ti o kù ninu nwọn wọ̀ inu ilu
olodi lọ,
21 Gbogbo enia si pada si ibudó sọdọ
Joṣua ni Makkeda li alafia: kò sí ẹni kan
ti o yọ ahọn rẹ̀ si awọn ọmọ Israeli.
22 Nigbana ni Joṣua wipe, Ẹ ṣi ẹnu ihò
na, ki ẹ si mú awọn ọba mararun na jade
kuro ninu ihò tọ̀ mi wá.
23 Nwọn si ṣe bẽ, nwọn si mú awọn ọba
mararun nì jade lati inu ihò na tọ̀ ọ wá,
ọba Jerusalemu, ọba Hebroni, ọba Jarmutu,
ọba Lakiṣi, ati ọba Egloni.
24 O si ṣe, nigbati nwọn mú awọn ọba
na tọ̀ Joṣua wá, ni Josua pè gbogbo awọn
ọkọnrin Israeli, o si wi fun awọn olori
awọn ọmọ-ogun ti o bá a lọ pe, Ẹ sunmọ
ihin, ẹ si fi ẹsẹ̀ nyin lé ọrùn awọn ọba
wọnyi. Nwọn si sunmọ wọn, nwọn si gbé
ẹsẹ̀ wọn lé wọn li ọrùn.
25 Joṣua si wi fun wọn pe, Ẹ má ṣe bẹ̀ru,
ẹ má si ṣe fòya; ẹ ṣe giri, ki ẹ si mu àiya
le: nitoripe bayi li OLUWA yio ṣe si awọn
ọtá nyin gbogbo ti ẹnyin mbájà.
26 Lẹhin'na ni Joṣua si kọlù wọn, o si pa
wọn, o si so wọn rọ̀ lori igi marun: nwọn
si sorọ̀ lori igi titi di aṣalẹ.
27 O si ṣe li akokò ìwọ-õrùn, Joṣua paṣẹ,
nwọn si sọ̀ wọn kalẹ kuro lori igi, nwọn si
gbé wọn sọ sinu ihò na ninu eyiti nwọn ti
sapamọ́ si, nwọn si fi okuta nla di ẹnu ihò
na, ti o wà titi di oni-oloni.
28 Li ọjọ́ na ni Joṣua kó Makkeda, o si
fi oju idà kọlù u, ati ọba rẹ̀; o pa wọn run
patapata, ati gbogbo ọkàn ti mbẹ ninu rẹ̀,
kò kù ẹnikan silẹ: o si ṣe si ọba Makkeda
gẹgẹ bi o ti ṣe si ọba Jeriko.
29 Joṣua si kọja lati Makkeda lọ si
Libna, ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀, o si fi ijà
fun Libna:
30 OLUWA si fi i lé Israeli lọwọ pẹlu, ati
ọba rẹ̀: o si fi oju idà kọlù u, ati gbogbo
ọkàn ti o wà ninu rẹ̀: kò kù ẹnikan ninu
rẹ̀; o si ṣe si ọba rẹ̀ gẹgẹ bi o ti ṣe si ọba
Jeriko.
31 Joṣua si kọja lati Libna lọ si Lakiṣi,
ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀, o si dótì i, o si
fi ìja fun u.
32 OLUWA si fi Lakiṣi lé Israeli lọwọ, o
si kó o ni ijọ́ keji, o si fi oju idà kọlù u,
ati gbogbo ọkàn ti o wà ninu rè, gẹgẹ bi
gbogbo eyiti o ṣe si Libna.
33 Nigbana ni Horamu ọba Geseri gòke
lati ràn Lakiṣi lọwọ; Joṣua si kọlù u ati
awọn enia rẹ̀, tobẽ ti kò fi kù ẹnikan silẹ
fun u.
34 Lati Lakiṣi Joṣua kọja lọ si Egloni,
ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀; nwọn si dótì i,
nwọn si fi ijà fun u;
35 Nwọn si kó o li ọjọ́ na, nwọn si fi oju
idà kọlù u, ati gbogbo ọkàn ti mbẹ ninu rẹ̀
li o parun patapata li ọjọ́ na, gẹgẹ bi gbo-
gbo eyiti o ṣe si Lakiṣi.
36 Joṣua si gòke lati Egloni lọ si Heb-
roni, ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀; nwọn si
fi ijà fun u:
37 Nwọn si kó o, nwọn si fi oju idà kọlù
u, ati ọba rẹ̀, ati gbogbo ilu rẹ̀, ati gbogbo
ọkàn ti o wà ninu rẹ̀; kò kù ẹnikan silẹ,
gẹgẹ bi gbogbo eyiti o ṣe si Egloni; o si pa
a run patapata, ati gbogbo ọkàn ti o wà
ninu rẹ̀.
38 Joṣua si pada lọ si Debiri, ati gbogbo
Israeli pẹlu rẹ̀; o si fi ijà fun u:
39 O si kó o, ati ọba rẹ̀, ati gbogbo ilu
rẹ̀; nwọn si fi oju idà kọlù wọn; nwọn si
pa gbogbo ọkàn ti mbẹ ninu rẹ̀ run pata-
pata; kò si kù ẹnikan silẹ: gẹgẹ bi o ti ṣe
si Hebroni, bẹ̃li o ṣe si Debiri, ati ọba rẹ̀;
ati gẹgẹ bi o ti ṣe si Libna, ati ọba rẹ̀.
40 Bẹ̃ni Joṣua kọlù gbogbo ilẹ, ilẹ òke,
ati ti Gusù, ati ti pẹtẹlẹ̀, ati ti ẹsẹ̀-òke, ati
awọn ọba wọn gbogbo; kò kù ẹnikan silẹ:
ṣugbọn o pa ohun gbogbo ti nmí run
patapata, gẹgẹ bi OLUWA, Ọlọrun Israeli,
ti pa a laṣẹ.
41 Joṣua si kọlù wọn lati Kadeṣi-barnea
lọ titi dé Gasa, ati gbogbo ilẹ Goṣeni, ani
titi dé Gibeoni.
42 Ati gbogbo awọn ọba wọnyi ati ilẹ
wọn, ni Joṣua kó ni ìgba kanna, nitoriti
OLUWA, Ọlọrun Israeli, jà fun Israeli.
43 Joṣua si pada, ati gbogbo Israeli pẹlu
rẹ̀, si ibudó ni Gilgali.

## ORI 11.

O SI ṣe, nigbati Jabini ọba Hasoru gbọ́
nkan wọnyi, o ranṣẹ si Jobabu ọba
Madoni, ati si ọba Ṣimroni, ati si ọba
Akṣafu,
2 Ati si awọn ọba ti mbẹ ni ìha ariwa,

Digitized by Google

lori òke, ati ti pẹtẹlẹ̀ ni ìha gusù ti Kin-
nerotu, ati ni ilẹ titẹju, ati ni ilẹ òke Doru
ni ìha ìwọ-õrùn,
3 Ati si awọn ara Kenaani ni ìha ìla-
õrùn ati ni ìha ìwọ-õrùn, ati awọn Amori,
ati si awọn Hitti, ati si awọn Perissi, ati si
awọn Jebusi lori òke, ati si awọn Hifi nisalẹ
Hermoni ni ilẹ Mispa.
4 Nwọn si jade, awọn ati gbogbo ogun
wọn pẹlu wọn, ọ̀pọlọpọ enia, bi yanrin ti
mbẹ li eti okun fun ọ̀pọ, ati ẹṣin ati kẹkẹ́
pipọ̀pipọ.
5 Gbogbo awọn ọba wọnyi si pejọ pọ̀,
nwọn wá nwọn si dó ṣọkan ni ibi omi
Meromu, lati fi ijà fun Israeli.
6 OLUWA si wi fun Joṣua pe, Máṣe
bẹ̀ru nitori wọn: nitori li ọla li akokò yi
emi o fi gbogbo wọn tọrẹ niwaju Israeli ni
pipa: iwọ o já patì ẹṣin wọn, iwọ o si fi iná
sun kẹkẹ́ wọn.
7 Bẽni Joṣua, ati gbogbo awọn ọmọ-ogun
pẹlu rẹ̀, yọ si wọn lojijì ni ibi omi Meromu,
nwọn si kọlù wọn.
8 OLUWA si fi wọn lé Israeli lọwọ, nwọn
si kọlù wọn, nwọn si lé wọn titi dé Sidoni
nla ati titi dé Misrefoti-maimu, ati dé
afonifoji Mispa ni ìha ìla-õrùn; nwọn si pa
wọn tobẽ ti kò kù ẹnikan silẹ fun wọn.
9 Joṣua si ṣe si wọn gẹgẹ bi OLUWA ti
paṣẹ fun u: o já patì ẹṣin wọn, o si fi iná
sun kẹkẹ́ wọn.
10 Joṣua si pada li akokò na, o si kó
Hasoru, o si fi idà pa ọba rẹ̀: nitori li
atijọrí Hasoru li olori gbogbo ilẹ-ọba wọnni.
11 Nwọn si fi oju idà pa gbogbo ọkàn ti
mbẹ ninu rẹ̀, nwọn run wọn patapata: a
kò kù ẹnikan ti nmí silẹ: o si fi iná kun
Hasoru.
12 Ati gbogbo ilu awọn ọba wọnni, ati
gbogbo ọba wọn, ni Joṣua kó, o si fi oju idà
kọlù wọn, o si pa wọn run patapata, gẹgẹ
bi Mose iranṣẹ OLUWA ti palaṣẹ.
13 Ṣugbọn awọn ilu ti o duro lori òke
wọn, Israeli kò sun ọkan ninu wọn, bikoṣe
Hasoru nikan; eyi ni Joṣua fi iná sun.
14 Ati gbogbo ikogun ilu wọnyi, ati
ohunọ̀sin, ni awọn ọmọ Israeli kó fun ara
wọn; ṣugbọn gbogbo awọn ọkọnrin ni
nwọn fi oju idà kọlù, titi nwọn fi pa wọn
run, nwọn kò kù ẹnikan silẹ ti nmí.
15 Gẹgẹ bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose
iranṣẹ rẹ̀, bẽni Mose paṣẹ fun Joṣua: bẽni
Joṣua si ṣe; on kò kù ohun kan silẹ ninu
gbogbo ohun ti OLUWA palaṣẹ fun Mose.
16 Bẽni Joṣua gbà gbogbo ilẹ na, ilẹ
òke, ati gbogbo ilẹ Gusù, ati gbogbo ilẹ
Goṣeni, ati ilẹ titẹju, ati pẹtẹlẹ̀, ati ilẹ òke
Israeli, ati ilẹ titẹju rẹ̀;
17 Lati òke Halaki lọ, ti o lọ soke Seiri,
ani dé Baali-gadi ni afonifoji Lebanoni
nisalẹ òke Hermoni: ati gbogbo awọn ọba
wọn li o kó, o si kọlù wọn, o si pa wọn.
18 Joṣua si bá gbogbo awọn ọba wọnni
jagun li ọjọ́ pipọ̀.
19 Kò sí ilu kan ti o bá awọn ọmọ
Israeli ṣọrẹ, bikoṣe awọn Hifi awọn ara
ilu Gibeoni: gbogbo wọn ni nwọn fi ogun
gbà.
20 Nitori lati ọdọ OLUWA li a ti mu
ọkàn wọn le, ki nwọn ki o le jade ogun tọ̀
Israeli wá, ki o le pa wọn run patapata, ki
nwọn ki o má si ṣe ri ojurere, ṣugbọn ki o
le pa wọn run, gẹgẹ bi OLUWA ti paṣẹ fun
Mose.
21 Li akokò na ni Joṣua wá, ti o si ke
awọn ọmọ Anaki kuro ni ilẹ òke, kuro ni
Hebroni, kuro ni Debiri, kuro ni Anabu,
ati kuro ni gbogbo ilẹ òke Juda, ati kuro
ni gbogbo ilẹ òke Israeli: Joṣua run wọn
patapata pẹlu ilu wọn.
22 Kò kù ẹnikan ninu awọn ọmọ Anaki
ni ilẹ awọn ọmọ Israeli: bikoṣe ni Gasa, ni
Gati, ati ni Aṣdodu, ni nwọn kù si.
23 Bẽni Joṣua gbà gbogbo ilẹ na, gẹgẹ
bi ohun gbogbo ti OLUWA ti wi fun Mose;
Joṣua si fi i fun Israeli ni ilẹ-iní, gẹgẹ bi
ipín wọn nipa ẹ̀ya wọn. Ilẹ na si simi
lọwọ ogun.

## ORI 12.

NJẸ wọnyi ni awọn ọba ilẹ na, ti awọn
ọmọ Israeli pa, ti nwọn si gbà ilẹ
wọn li apa keji Jordani, ni ìha ìla-õrùn,
lati odò Arnoni lọ titi dé òke Hermoni, ati
gbogbo pẹtẹlẹ̀ ni ìha ìla-õrun:
2 Sihoni ọba Amori, ti ngbé Heṣboni, ti
o si jọba lati Aroeri, ti mbẹ leti odò Arnoni,
ati ilu ti o wà lãrin afonifoji na, ati àbọ
Gileadi, ani titi dé odò Jaboku, àgbegbe
awọn ọmọ Ammoni;
3 Ati ni pẹtẹlẹ̀ lọ dé okun Kinnerotu
ni iha ìla-õrùn, ati titi dé okun pẹtẹlẹ̀, ani
Okun Iyọ̀ ni ìha ìla-õrùn, li ọna Beti-
jeṣimotu; ati lati gusù lọ nisalẹ ẹsẹ̀-òke
Pisga:
4 Ati àgbegbe Ogu ọba Baṣani, ọkan
ninu awọn ti o kù ninu awọn Refaimu,
ẹniti ngbé Aṣtarotu ati Edrei,
5 O si jọba li òke Hermoni, ati ni
Saleka, ati ni gbogbo Baṣani, titi o fi dé
àgbegbe awọn Geṣuri ati awọn Maakati,
ati àbọ Gileadi, àla Sihoni ọba Heṣboni

Digitized by Google

6 Mose iranṣẹ OLUWA ati awọn ọmọ
Israeli kọlù wọn: Mose iranṣẹ OLUWA si
fi i fun awọn ọmọ Reubeni ni ilẹ-iní, ati
fun awọn ọmọ Gadi, ati fun àbọ ẹ̀ya
Manasse.
7 Wọnyi li awọn ọba ilẹ na, ti Joṣua ati
awọn ọmọ Israeli pa li apa ihin Jordani, ni
ìwọ-õrùn, lati Baali-gadi li afonifoji Leba-
noni ani titi dé òke Halaki, li ọ̀na òke
Seiri; ti Joṣua fi fun awọn ẹ̀ya Israeli ni
ilẹ-iní gẹgẹ bi ipín wọn.
8 Ni ilẹ òke, ati ni ilẹ titẹju, ati ni
pẹtẹlẹ̀, ati li ẹsẹ̀-òke, ati li aginjù, ati ni
Gusù; awọn Hitti, awọn Amori, ati awọn
ara Kenaani, awọn Perissi, awọn Hifi, ati
awọn Jebusi:
9 Ọba Jeriko, ọkan; ọba Ai, ti o wà
lẹba Beteli, ọkan.
10 Ọba Jerusalemu, ọkan; ọba Hebroni,
ọkan;
11 Ọba Jarmutu, ọkan; ọba Lakiṣi,
ọkan;
12 Ọba Egloni, ọkan; ọba Geseri, ọkan;
13 Ọba Debiri, ọkan; ọba Gederi, ọkan;
14 Ọba Horma, ọkan; ọba Aradi, ọkan;
15 Ọba Libna, ọkan; ọba Adullamu,
ọkan;
16 Ọba Makkeda, ọkan; ọba Beteli,
ọkan;
17 Ọba Tappua, ọkan; ọba Heferi,
ọkan;
18 Ọba Afeki, ọkan; ọba Laṣaroni,
ọkan;
19 Ọba Madoni, ọkan; ọba Hasoru,
ọkan;
20 Ọba Ṣimroni-meroni, ọkan; ọba
Akṣafu, ọkan;
21 Ọba Taanaki, ọkan; ọba Megiddo,
ọkan;
22 Ọba Kedeṣi, ọkan; ọba Jokneamu ti
Karmeli, ọkan;
23 Ọba Doru, li òke Doru, ọkan; ọba
awọn orilẹ-ède Gilgali, ọkan;
24 Ọba Tirsa, ọkan; gbogbo awọn ọba
na jẹ́ mọkanlelọgbọ̀n.

## ORI 13.

JOṢUA si gbó o si pọ̀ li ọjọ́; OLUWA si
wi fun u pe, Iwọ gbó, iwọ si pọ̀ li ọjọ́,
ilẹ pipọ̀pipọ si kù lati gbà.
2 Eyi ni ilẹ ti o kù; gbogbo ilẹ awọn
Filistini, ati gbogbo Geṣuri;
3 Lati Ṣihori, ti mbẹ niwaju Egipti, ani
titi dé àgbegbe Ekroni ni ìha ariwa, ti a
kà kún awọn ara Kenaani: awọn ijoye
Filistia marun; awọn ara Gasa, ati awọn
ara Aṣdodi awọn ara Aṣkeloni, awọn Gitti,
ati awọn ara Ekroni; awọn Affimu pẹlu ni
gusù:
4 Gbogbo ilẹ awọn ara Kenaani, ati
Meara ti awọn ara Sidoni, dé Afeki, titi
dé àgbegbe awọn Amori:
5 Ati ilẹ awọn Gebali, ati gbogbo Le-
banoni ni ìha ìla-õrùn, lati Baali-gadi
nisalẹ òke Hermoni titi o fi dé atiwọ̀
Hamati:
6 Gbogbo awọn ara ilẹ òke lati Lebanoni
titi dé Misrefoti-maimu, ani gbogbo awọn
ara Sidoni; awọn li emi o lé jade kuro
niwaju awọn ọmọ Israeli: kìki ki iwọ ki o
fi keké pín i fun Israeli ni ilẹ-iní, gẹgẹ bi
mo ti paṣẹ fun ọ.
7 Njẹ nitorina pín ilẹ yi ni ilẹ-iní
fun awọn ẹ̀ya mẹsan, ati fun àbọ ẹ̀ya
Manasse.
8 Pẹlu rẹ̀ awọn ọmọ Reubeni ati awọn
ọmọ Gadi ti gbà ilẹ-iní wọn, ti Mose fi fun
wọn ni ìha keji Jordani ni ìha ìla õrùn, bi
Mose iranṣẹ OLUWA ti fi fun wọn;
9 Lati Aroeri lọ, ti mbẹ leti afonifoji
Arnoni, ati ilu ti mbẹ lãrin afonifoji na,
ati gbogbo pẹtẹlẹ̀ Medeba titi dé Diboni;
10 Ati gbogbo ilu Sihoni ọba awọn
Amori, ti o jọba ni Heṣboni, titi dé àgbegbe
awọn ọmọ Ammoni:
11 Ati Gileadi, ati àgbegbe awọn Geṣuri
ati awọn Maakati, ati gbogbo òke Hermoni,
ati gbogbo Baṣani dé Saleka;
12 Gbogbo ilẹ ọba Ogu ni Baṣani, ti o
jọba ni Aṣtarotu ati ni Edrei, ẹniti o kù
ninu awọn Refaimu iyokù: nitori awọn
wọnyi ni Mose kọlù, ti o si lé jade.
13 Ṣugbọn awọn ọmọ Israeli kò lé awọn
Geṣuri, tabi awọn Maakati jade: ṣugbọn
awọn Geṣuri ati awọn Maakati ngbé ãrin
awọn ọmọ Israeli titi di oni.
14 Kìki ẹ̀ya Lefi ni on kò fi ilẹ-iní fun;
ẹbọ OLUWA, Ọlọrun Israeli, ti a fi iná ṣe ni
iní wọn, gẹgẹ bi o ti wi fun wọn.
15 Mose si fi fun ẹ̀ya awọn ọmọ Reubeni,
gẹgẹ bi idile wọn.
16 Àla wọn bẹ̀rẹ lati Aroeri lọ, ti mbẹ
leti afonifoji Arnoni, ati ilu ti mbẹ lãrin
afonifoji ni, ati gbogbo pẹtẹlẹ̀ ti mbẹ ni
ìha Medeba;
17 Heṣboni, ati gbogbo ilu rẹ̀ ti mbẹ ni
pẹtẹlẹ̀; Diboni, ati Bamoti-baali, ati Beti-
baali-meoni;
18 Ati Jahasa, ati Kedemoti, ati Mefaati;
19 Ati Kiriataimu, ati Sibma, ati Sareti-
ṣahari ni òke afonifoji na;

Digitized by Google

20 Ati Beti-peori, ati orisun Pisga, ati Beti-jeṣimotu;
21 Ati gbogbo ilu pẹtẹlẹ̀ na, ati gbogbo ilẹ-ọba Sihoni ọba awọn Amori, ti o jọba ni Heṣboni, ti Mose kọlù pẹlu awọn ọmọ alade Midiani, Efi, ati Rekemu, ati Suri, ati Huri, ati Reba, awọn ọmọ alade Sihoni, ti ngbé ilẹ na.
22 Ati Balaamu ọmọ Beori, alafọṣẹ, ni awọn ọmọ Israeli fi idà pa pẹlu awọn ti nwọn pa.
23 Ati àla awọn ọmọ Reubeni ni Jordani, ati àgbegbe rẹ̀. Eyi ni ilẹ iní awọn ọmọ Reubeni gẹgẹ idile wọn, awọn ilu ati ileto wọn.
24 Mose si fi ilẹ fun ẹ̀ya Gadi, ani fun awọn ọmọ Gadi, gẹgẹ bi idile wọn.
25 Àla wọn bẹ̀rẹ ni Jaseri, ati gbogbo ilu Gileadi, ati àbọ ilẹ awọn ọmọ Ammoni, titi dé Aroeri ti mbẹ niwaju Rabba;
26 Ati lati Heṣboni titi dé Ramatu-mispe, ati Betonimu; ati lati Mahanaimu titi dé àgbegbe Debiri;
27 Ati ni afonifoji, Beti-haramu, ati Beti-nimra, ati Sukkotu, ati Safoni, iyokù ilẹ-ọba Sihoni ọba Heṣboni, Jordani ati àgbegbe rẹ̀, titi dé ìha opín okun Kinnereti ni ìha keji Jordani ni ìha ìla-õrùn.
28 Eyi ni ilẹ-iní awọn ọmọ Gadi gẹgẹ bi idile wọn, ilu wọn ati ileto wọn.
29 Mose si fi ilẹ-iní fun àbọ ẹ̀ya Manasse: o si jẹ́ ti àbọ ẹ̀ya awọn ọmọ Manasse gẹgẹ bi idile wọn.
30 Àla wọn si bẹ̀rẹ lati Mahanaimu lọ, gbogbo Baṣani, gbogbo ilẹ-ọba Ogu ọba Baṣani, ati gbogbo ilu Jairi, ti mbẹ ni Baṣani, ọgọta ilu:
31 Ati àbọ Gileadi, ati Aṣtarotu, ati Edrei, ilu ilẹ-ọba Ogu ni Baṣani, jẹ́ ti awọn ọmọ Makiri, ọmọ Manasse, ani ti àbọ awọn ọmọ Makiri, gẹgẹ bi idile wọn.
32 Wọnyi li awọn ilẹ-iní na ti Mose pín ni iní ni pẹtẹlẹ̀ Moabu, li apa keji Jordani, lẹba Jeriko ni ìha ìla-õrùn.
33 Ṣugbọn ẹ̀ya Lefi ni Mose kò fi ilẹ-iní fun: OLUWA, Ọlọrun Israeli, ni iní wọn, gẹgẹ bi o ti wi fun wọn.

## ORI 14.

WỌNYI si ni ilẹ-iní ti awọn ọmọ Israeli gbà ni iní ni ilẹ Kenaani, ti Eleasari alufa, ati Joṣua ọmọ Nuni, ati awọn olori awọn baba ẹ̀ya awọn ọmọ Israeli pín fun wọn,
2 Keké ni nwọn fi ní ilẹ-iní wọn, gẹgẹ bi OLUWA ti palaṣẹ lati ọwọ́ Mose wá, fun awọn ẹ̀ya mẹsan, ati àbo ẹ̀ya ni.
3 Nitori Mose ti fi ilẹ-iní fun awọn ẹ̀ya meji ati àbọ ẹ̀ya li apa keji Jordani: ṣugbọn awọn ọmọ Lefi ni on kò fi ilẹ-iní fun lãrin wọn.
4 Nitoripe ẹ̀ya meji ni ẹ̀ya awọn ọmọ Josefu, Manasse ati Efraimu: nitorina nwọn kò si fi ipín fun awọn ọmọ Lefi ni ilẹ na, bikoṣe ilu lati ma gbé, pẹlu àgbegbe ilu wọn fun ohunọ̀sin wọn ati ohun-iní wọn.
5 Gẹgẹ bi OLUWA ti paṣẹ fun Mose, bẽni awọn ọmọ Israeli ṣe, nwọn si pín ilẹ na.
6 Nigbana ni awọn ọmọ Juda wá sọdọ Joṣua ni Gilgali: Kalebu ọmọ Jefunne ti Kenissi si wi fun u pe, Iwọ mọ̀ ohun ti OLUWA wi fun Mose enia Ọlọrun nipa temi tirẹ ni Kadeṣi-barnea.
7 Ẹni ogoji ọdún ni mi nigbati Mose iranṣẹ OLUWA rán mi lati Kadeṣi-barnea lọ ṣamí ilẹ na; mo si mú ìhin fun u wá gẹgẹ bi o ti wà li ọkàn mi.
8 Ṣugbọn awọn arakọnrin mi ti o gòke lọ, já awọn enia li àiya: ṣugbọn emi tọ̀ OLUWA Ọlọrun mi lẹhin patapata.
9 Mose si bura li ọjọ́ na wipe, Nitõtọ ilẹ ti ẹsẹ̀ rẹ ti tẹ̀ nì, ilẹ-iní rẹ ni yio jẹ́, ati ti awọn ọmọ rẹ lailai, nitoriti iwọ tọ̀ OLUWA Ọlọrun mi lẹhin patapata.
10 Njẹ nisisiyi, kiyesi i, OLUWA da mi si gẹgẹ bi o ti wi, lati ọdún marun-lelogoji yi wá, lati ìgba ti OLUWA ti sọ ọ̀rọ yi fun Mose, nigbati Israeli nrìn kiri li aginjù: si kiyesi i nisisiyi, emi di ẹni arundilãdọrun ọdún li oni.
11 Sibẹ̀ emi lí agbara li oni gẹgẹ bi mo ti ní li ọjọ́ ti Mose rán mi lọ: gẹgẹ bi agbara mi ti ri nigbana, ani bẹ̃li agbara mi ri nisisiyi, fun ogun, ati lati jade ati lati wọle.
12 Njẹ nitorina fi òke yi fun mi, eyiti OLUWA wi li ọjọ́ na; nitoriti iwọ gbọ́ li ọjọ́ na bi awọn ọmọ Anaki ti wà nibẹ̀, ati ilu ti o tobi, ti o si ṣe olodi: bọya OLUWA yio wà pẹlu mi, emi o si lé wọn jade, gẹgẹ bi OLUWA ti wi.
13 Joṣua si sure fun u; o si fi Hebroni fun Kalebu ọmọ Jefunne ni ilẹ-iní.
14 Nitorina Hebroni di ilẹ-iní Kalebu ọmọ Jefunne ti Kenissi titi di oni-oloni; nitoriti o tọ̀ OLUWA Ọlọrun Israeli lẹhin patapata.
15 Orukọ Hebroni lailai rí a nia jẹ́ Kiriati-arba; Arba jẹ́ enia nla kan nimu

Digitized by Google

awọn ọmọ Anaki. Ilẹ na si simi lọwọ
ogun.

## ORI 15.

ILẸ ẹ̀ya awọn ọmọ Juda gẹgẹ bi idile wọn
si dé àgbegbe Edomu, ni aginjù Sini,
ni ìha gusù, ni apa ipẹkun gusù.
2 Ati àla gusù wọn ni lati eti Okun Iyọ̀
lọ, lati ibi kọrọ omi nì lọ ti o dojukọ ìha
gusù:
3 O si lọ si apa gusù òke Akrabbimu, o
si lọ si Sini, o si gòke lọ ni ìha gusù
Kadeṣi-barnea, o si lọ ni ìha Hesroni, o si
gòke lọ si Adari, o si yiká lọ dé Karka:
4 Lati ibẹ̀ o lọ dé Asmoni, o si nà lọ si
odò Egipti; opín ilẹ na si yọ si okun: eyi
ni yio jẹ́ àla ni gusù nyin.
5 Ati àla ìha ila-õrùn ni Okun Iyọ̀, ani
titi dé ipẹkun Jordani. Ati àla apa ariwa
ni lati kọrọ okun nì wá dé ipẹkun Jor-
dani:
6 Àla na si gòke lọ si Beti-hogla, o si
kọja lọ ni ìha ariwa Beti-araba; àla na si
gòke lọ si okuta Bohani ọmọ Reubeni:
7 Àla na si gòke lọ si Debiri lati afoni-
foji Akoru, ati bẹ̃ lọ si ìha ariwa, ti o dojukọ
Gilgali, ti mbẹ niwaju òke Adummimu, ti
mbẹ ni ìha gusù odò na: àla si kọja si apa
omi Eni-ṣemeṣi, o si yọ si Eni-rogeli:
8 Àla na si gòke lọ si ìha afonifoji ọmọ
Hinnomu si ìha gusù ti Jebusi (ti iṣe
Jerusalemu): àla na si gòke lọ si ori òke
nla ti mbẹ niwaju afonifoji Hinnomn ni
ìha ìwọ-õrùn, ti mbẹ ni ipẹkun afonifoji
Refaimu ni ìha ariwa:
9 A si fà àla na lati ori òke lọ si isun
omi Neftea, o si nà lọ si ilu òke Efroni; a
si fà àla na lọ si Baala, (ti iṣe Kirjati-jea-
rimu:)
10 Àla na yi lati Baala lọ si ìha ìwọ-
õrùn si òke Seiri, o si kọja lọ si ẹba òke
Jearimu (ti ṣe Kesaloni), ni ìha ariwa, o si
sọkalẹ lọ si Beti-ṣemeṣi o si kọja lọ si Beti-
ṣemeṣi, o si kọja lọ si Timna:
11 Àla na si kọja lọ si ẹba Ekroni si ìha
ariwa: a si fà àla na lọ dé Ṣikroni, o si
kọja lọ si òke Baala, o si yọ si Jabneeli;
àla nã si yọ si okun.
12 Ala ìwọ-õrùn si dé okun nla, ati
àgbegbe rẹ̀. Eyi ni àla awọn ọmọ Juda
yiká kiri gẹgẹ bi idile wọn.
13 Ati fun Kalebu ọmọ Jefunne li o fi
ipín fun lãrin awọn ọmọ Juda, gẹgẹ bi aṣẹ
OLUWA fun Joṣua, ani Kiriati-arba (ti iṣe
Hebroni); Arba si ni baba Anaki.
14 Kalebu si lé awọn ọmọ Anaki mẹta
kuro nibẹ̀, Ṣeṣai, ati Ahimani, ati Talmai,
awọn ọmọ Anaki.
15 O si gòke lati ibẹ̀ tọ̀ awọn ara Debiri
lọ: orukọ Debiri lailai rí ni Kiriati-seferi.
16 Kalebu si wipe, Ẹniti o ba kọlù
Kiriati-seferi, ti o si kó o, on li emi o fi
Aksa ọmọbirin mi fun li aya.
17 Otnieli ọmọ Kenasi, arakọnrin Kale-
bu, si kó o: o si fi Aksa ọmọbirin rẹ̀ fun u
li aya.
18 O si ṣe, bi Aksa ti dé ọdọ rẹ̀, o mu u
bère ọ̀rọ kan lọwọ baba rẹ̀: Aksa si sọkalẹ
lori kẹtẹkẹtẹ rẹ̀; Kalebu si wi fun u pe,
Kini iwọ nfẹ́?
19 On si dahùn pe, Ta mi li ọrẹ kan;
nitoriti iwọ ti fun mi ni ilẹ Gusù, fun mi
ni isun omi pẹlu. O si fi isun òke ati isun
isalẹ fun u.
20 Eyi ni ilẹ-iní ẹ̀ya awọn ọmọ Juda
gẹgẹ bi idile wọn.
21 Ilu ipẹkun ẹ̀ya awọn ọmọ Juda li
àgbegbe Edomu ni Gusù ni Kabseeli, ati
Ederi, ati Jaguri;
22 Ati Kina, ati Dimona, ati Adada;
23 Ati Kedeṣi, ati Hasori, ati Itnani;
24 Sifu, ati Telemu, ati Bealotu;
25 Ati Haṣori-hadatta, ati Keriotu-
hesroni (ti iṣe Hasori);
26 Amamu, ati Ṣema, ati Molada;
27 Ati Hasari-gada, ati Heṣmoni, ati
Beti-peleti;
28 Ati Hasari-ṣuali, ati Beeri-ṣeba, ati
Bisi-otia;
29 Baala, ati Iimu, ati Esemu;
30 Ati Eltoladi, ati Kesili, ati Horma;
31 Ati Siklagi, ati Madmanna, ati
Sansanna;
32 Ati Lebaotu, ati Ṣilhimu, ati Aini,
ati Rimmoni: gbogbo ilu na jasi mọkandi-
lọgbọ̀n, pẹlu ileto wọn.
33 Ni pẹtẹlẹ̀, Eṣtaoli, ati Sora, ati
Aṣna;
34 Ati Sanoa, ati Eni-gannimu Tappua,
ati Enamu;
35 Jarmutu, ati Adullamu, Soko, ati
Aseka;
36 Ati Ṣaaraimu, ati Aditaimu, ati
Gedera, ati Gederotaimu; ilu mẹrinla pẹlu
ileto wọn.
37 Senani, ati Hadaṣa, ati Migdaligadi;
38 Ati Dilani, ati Mispe, ati Jokteeli;
39 Lakiṣi, ati Boskati, ati Egloni;
40 Ati Kabboni, ati Lamamu, ati Kit-
liṣi;
41 Ati Gederotu, Beti-dagoni, ati Naa-

Digitized by Google

ma, ati Makkeda; ilu mẹrindilogun pẹlu
ileto wọn.
42 Libna, ati Eteri, ati Aṣani;
43 Ati Ifta, ati Aṣna, ati Nesibu;
44 Ati Keila, ati Aksibu, ati Mareṣa;
ilu mẹsan pẹlu ileto wọn.
45 Ekroni, pẹlu awọn ilu rẹ̀ ati awọn
ileto rẹ̀:
46 Lati Ekroni lọ ani titi dé okun,
gbogbo eyiti mbẹ leti Aṣdodu, pẹlu ileto
wọn.
47 Aṣdodu, pẹlu ilu rẹ̀ ati ileto rẹ̀;
Gasa, pẹlu ilu rẹ̀ ati ileto rẹ̀; dé odò
Egipti, ati okun nla, ati àgbegbe rẹ̀.
48 Ati ni ilẹ òke, Ṣamiri, ati Jattiri, ati
Soko;
49 Ati Dana, ati Kiriati-sana (ti ṣe
Debiri);
50 Ati Anabu, ati Eṣtemo, ati Animu;
51 Ati Goṣeni, ati Holoni, ati Gilo; ilu
mọkanla pẹlu ileto wọn.
52 Arabu, ati Duma, ati Eṣani;
53 Ati Janimu, ati Beti-tappua, ati
Afeka;
54 Ati Humta, ati Kiriati-arba (ti iṣe
Hebroni), ati Siori; ilu mẹsan pẹlu ileto
wọn.
55 Maoni, Karmeli, ati Sifu, ati Juta;
56 Ati Jesreeli, ati Jokdeamu, ati
Sanoa;
57 Kaini, Gibea, ati Timna; ilu mẹwa
pẹlu ileto wọn.
58 Halhulu, Beti-suru, ati Gedori;
59 Ati Maarati, ati Beti-anotu, ati Elte-
koni; ilu mẹfa pẹlu ileto wọn.
60 Kiriati-baali (ti iṣe Kiriati-jearimu),
ati Rabba; ilu meji pẹlu ileto wọn.
61 Li aginjù, Bet-araba, Middini, ati
Sekaka;
62 Ati Nibṣani, ati Ilu Iyọ̀, ati Enigedi;
ilu mẹfa pẹlu ileto wọn.
63 Bi o si ṣe ti awọn Jebusi nì, awọn ara
Jerusalemu, awọn ọmọ Juda kò le lé wọn
jade: ṣugbọn awọn Jebusi mbá awọn ọmọ
Juda gbé ni Jerusalemu, titi di oni-oloni.

## ORI 16.

IPIN awọn ọmọ Josefu yọ lati Jordani
lọ ni Jeriko, ni omi Jeriko ni ìha ìla-
õrùn, ani aginjù, ti o gòke lati Jeriko lọ dé
ilẹ òke Beteli;
2 O si ti Beteli yọ si Lusi, o si kọja lọ
si àgbegbe Arki dé Atarotu;
3 O si sọkalẹ ni ìha ìwọ-õrùn si àgbegbe
Jafleti, dé àgbegbe Beti-horoni isalẹ, ani dé
Geseri: o si yọ si okun.
4 Bẹ̃li awọn ọmọ Josefu, Manasse ati
Efraimu, gbà ilẹ-iní wọn.
5 Àla awọn ọmọ Efraimu gẹgẹ bi idile
wọn li eyi: ani àla ilẹ-iní wọn ni ìha ìla-
õrùn ni Atarotu-adari, dé Beti-horoni òke;
6 Àla na si lọ si ìha ìwọ-õrùn si ìha
ariwa Mikmeta; àla na si yi lọ si ìha ìla-
õrùn dé Taanati-ṣilo, o si kọja lẹba rẹ̀ lọ ni
ìha ìla-õrùn Janoha;
7 O si sọkalẹ lati Janoha lọ dé Atarotu,
ati dé Naara, o si dé Jeriko, o si yọ si
Jordani.
8 Àla na jade lọ lati Tappua si ìha ìwọ-
õrùn titi dé odò Kana; o si yọ si okun.
Eyi ni ilẹ-iní ẹ̀ya awọn ọmọ Efraimu gẹgẹ
bi idile wọn;
9 Pẹlu ilu ti a yàsọtọ fun awọn ọmọ
Efraimu lãrin ilẹ-iní awọn ọmọ Manasse,
gbogbo ilu na pẹlu ileto wọn.
10 Nwọn kò si lé awọn ara Kenaani ti
ngbé Geseri jade: ṣugbọn awọn ara Kena-
ani joko lãrin Efraimu titi di oni yi, nwọn
si di ẹrú lati ma sìnru.

## ORI 17.

EYI si ni ipín ẹ̀ya Manasse; nitori on li
akọ́bi Josefu. Bi o ṣe ti Makiri
akọ́bi Manasse, baba Gileadi, nitori on ṣe
ologun, nitorina li o ṣe ní Gileadi ati
Baṣani.
2 Awọn ọmọ Manasse iyokù si ní ilẹ-iní
gẹgẹ bi idile wọn; awọn ọmọ Abieseri, ati
awọn ọmọ Heleki, ati awọn ọmọ Asrieli,
ati awọn ọmọ Ṣekemu, ati awọn ọmọ
Heferi, ati awọn ọmọ Ṣemida: awọn wọnyi
ni awọn ọmọ Manasse ọmọ Josefu gẹgẹ bi
idile wọn.
3 Ṣugbọn Selofehadi, ọmọ Heferi, ọmọ
Gileadi, ọmọ Makiri, ọmọ Manasse, kò ní
ọmọkọnrin, bikoṣe ọmọbirin: awọn wọnyi
si li orukọ awọn ọmọbirin rẹ̀, Mala, ati
Noa, Hogla, Milka, ati Tirsa.
4 Nwọn si wá siwaju Eleasari alufa, ati
siwaju Joṣua ọmọ Nuni, ati siwaju awọn
olori, wipe, OLUWA fi aṣẹ fun Mose lati fun
wa ni ilẹ-iní lãrin awọn arakọnrin wa:
nitorina o fi ilẹ-iní fun wọn lãrin awọn
arakọnrin baba wọn, gẹgẹ bi aṣẹ OLUWA.
5 Ipín mẹwa si bọ́ sọdọ Manasse, làika
ilẹ Gileadi ati Baṣani, ti mbẹ ni ìha keji
Jordani;
6 Nitoriti awọn ọmọbirin Manasse ní
ilẹ-iní lãrin awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin: awọn
ọmọ Manasse ọkọnrin iyokù si ní ilẹ
Gileadi.
7 Àla Manasse si lọ lati Aṣeri dé Mik-

Digitized by Google

meta, ti mbẹ niwaju Ṣekemu ; àla na si lọ
titi ni ìha ọtún, sọdọ awọn ara Eni-tappua.
8 Manasse li o ní ilẹ Tappua : ṣugbọn
Tappua li àla Manasse jẹ́ ti awọn ọmọ
Efraimu.
9 Àla rẹ̀ si sọkalẹ lọ si odò Kana, ni ìha
gusù odò na : ilu Efraimu wọnyi wà lãrin
awọn ilu Manasse : àla Manasse pẹlu si wà
ni ìha ariwa odò na, o si yọ si okun :
10 Ni ìha gusù ti Efraimu ni, ati ni ìha
ariwa ti Manasse ni, okun si ni àla rẹ̀ ;
nwọn si dé Aṣeri ni ìha ariwa, ati Issakari
ni ìha ìla-õrùn.
11 Manasse si ní ni Issakari ati ni
Aṣeri, Beti-ṣeani ati awọn ilu rẹ̀, ati
Ibleamu ati awọn ilu rẹ̀, ati awọn ara Dori
ati awọn ilu rẹ̀, ati awọn ara Endori ati
awọn ilu rẹ̀, ati awọn ara Taanaki ati awọn
ilu rẹ̀, ati awọn ara Megiddo ati awọn ilu
rẹ̀, ani òke mẹta na.
12 Ṣugbọn awọn ọmọ Manasse kò le gbà
ilu wọnyi ; awọn ara Kenaani si ngbé ilẹ
na.
13 O si ṣe, nigbati awọn ọmọ Israeli ndi
alagbara, nwọn mu awọn ara Kenaani sìn,
ṣugbọn nwọn kò lé wọn jade patapata.
14 Awọn ọmọ Josefu si wi fun Joṣua pe,
Ẽṣe ti iwọ fi fun mi ni ilẹ kan, ati ipín kan
ni ilẹ-iní, bẽni enia nla ni mi, niwọnbi
OLUWA ti bukún mi titi di isisiyi ?
15 Joṣua si da wọn lohùn pe, Bi iwọ ba
jẹ́ enia nla, gòke lọ si igbó, ki o si ṣanlẹ
fun ara rẹ nibẹ̀ ni ilẹ awọn Perissi ati ti
Refaimu ; bi òke Efraimu ba há jù fun ọ.
16 Awọn ọmọ Josefu si wipe, Òke na kò
to fun wa : gbogbo awọn ara Kenaani ti
ngbé ilẹ afonifoji si ní kẹkẹ́ irin, ati awọn
ti mbẹ ni Beti-ṣeani, ati awọn ilu rẹ̀, ati
awọn ti mbẹ ni afonifoji Jesreeli.
17 Joṣua si wi fun ile Josefu, ani fun
Efraimu ati fun Manasse pe, Enia nla ni
iwọ, iwọ si lí agbara pipọ̀ : iwọ ki yio ní
ipín kanṣoṣo :
18 Ṣugbọn ilẹ òke yio jẹ́ tirẹ ; nitoriti
iṣe igbó, iwọ o si ṣán a, ati ìna rẹ̀ yio jẹ́
tirẹ : nitoriti iwọ o lé awọn ara Kenaani
jade, bi o ti jẹ́ pe nwọn ní kẹkẹ́ irin nì, ti
o si jẹ́ pe nwọn lí agbara.

## ORI 18.

GBOGBO ijọ awọn ọmọ Israeli si pejọ ni
Ṣilo, nwọn si gbé agọ́ ajọ ró nibẹ̀ : a
si ṣẹgun ilẹ na niwaju wọn.
2 Ẹya meje si kù ninu awọn ọmọ
Israeli, ti kò ti igbà ilẹ-iní wọn.
3 Joṣua si wi fun awọn ọmọ Israeli pe,
Ẹnyin o ti lọra pẹ to lati lọ igbà ilẹ na, ti
OLUWA, Ọlọrun awọn baba nyin, ti fi fun
nyin ?
4 Ẹ yàn ọkọnrin mẹta fun ẹ̀ya kọkan :
emi o si rán wọn, nwọn o si dide, nwọn o
si là ilẹ na já, nwọn o si ṣe apejuwe rẹ̀ gẹgẹ
bi ilẹ-iní wọn ; ki nwọn ki o si pada tọ̀ mi
wá.
5 Nwọn o si pín i si ọ̀na meje : Juda yio
ma gbé ilẹ̀ rẹ̀ ni gusù, ile Josefu yio si ma
gbé ilẹ wọn ni ariwa.
6 Ẹnyin o si ṣe apejuwe ilẹ na li ọ̀na
meje, ẹnyin o si mú apejuwe tọ̀ mi wá
nihin, ki emi ki o le ṣẹ́ keké rẹ̀ fun nyin
nihin niwaju OLUWA Ọlọrun wa.
7 Nitoriti awọn ọmọ Lefi kò ní ipín
lãrin nyin ; nitori iṣẹ-alufa OLUWA ni iní
wọn : ati Gadi, ati Reubeni, ati àbọ ẹ̀ya
Manasse, ti gbà ilẹ-iní wọn na ni ìha keji
Jordani ni ìha ìla-õrùn, ti Mose iranṣẹ
OLUWA fi fun wọn.
8 Awọn ọkọnrin na si dide, nwọn si lọ :
Joṣua si paṣẹ fun awọn ti o lọ ṣe apejuwe
ilẹ na, wipe, Ẹ lọ, ki ẹ si rìn ilẹ na já, ki ẹ
si ṣe apejuwe rẹ̀, ki ẹ si pada tọ̀ mi wá, ki
emi ki o le ṣẹ́ keké fun nyin niwaju OLUWA
ni Ṣilo.
9 Awọn ọkọnrin na si lọ, nwọn si là
ilẹ na já, nwọn si ṣe apejuwe rẹ̀ sinu iwé ni
ilu ilu li ọ̀na meje, nwọn si pada tọ̀ Joṣua
wá, si ibudó ni Ṣilo.
10 Joṣua si ṣẹ́ keké fun wọn ni Ṣilo
niwaju OLUWA : nibẹ̀ ni Joṣua si pín ilẹ na
fun awọn ọmọ Israeli gẹgẹ bi ipín wọn.
11 Ilẹ ẹ̀ya awọn ọmọ Benjamini yọ jade,
gẹgẹ bi idile wọn : àla ipín wọn si yọ si
agbedemeji awọn ọmọ Juda ati awọn ọmọ
Josefu.
12 Àla wọn ni ìha ariwa si ti Jordani lọ ;
àla na si gòke lọ si ìha Jeriko ni ìha ariwa,
o si là ilẹ òke lọ ni iwọ-õrùn ; o si yọ si
aginjù Bet-afeni.
13 Àla na si ti ibẹ̀ lọ si Lusi, si ìha Lusi
(ti ṣe Beteli), ni ìha gusù ; àla na si
sọkalẹ lọ si Atarotu-adari, lẹba òke ti mbẹ
ni gusù Beti-horoni isalẹ.
14 A si fà àla na lọ, o si yi si ìha ìwọ-
õrùn lọ si gusù, lati òke ti mbẹ niwaju
Beti-horoni ni ìha gusù ; o si yọ si Kiriati-
baali (ti ṣe Kiriati-jearimu), ilu awọn ọmọ
Juda kan : eyi ni apa ìwọ-õrùn.
15 Ati apa gusù ni lati ipẹkun Kiriati-
jearimu, àla na si yọ si ìwọ-õrùn, o si yọ si
isun omi Neftoa :
16 Àla na si sọkalẹ lọ si ipẹkun òke ti
mbẹ niwaju afonifoji ọmọ Hinnomu, ti o si

Digitized by Google

mbẹ ni afonifoji Refaimu ni ìha ariwa ; o
si sọkalẹ lọ si afonifoji Hinnomu, si apa
Jebusi ni ìha gusù, o si sọkalẹ lọ si Eni-
rogeli ;
17 A si fà a lati ariwa lọ, o si yọ si Eni-
şemeşi, o si yọ si Gelilotu, ti o kọjusi òke
Adummimu ; o si sọkalẹ lọ si okuta Bohani
ọmọ Reubeni ;
18 O si kọja lọ si apa ibi ti o kọjusi
Araba ni ìha ariwa, o si sọkalẹ lọ si Araba :
19 Àla na si kọja lọ dé apa Beti-hogla
ni ìha ariwa : àla na si yọ ni ìha ariwa si
kòrọ Okun Iyọ̀, ni ipẹkun gusù ti Jordani :
eyi ni àla gusù.
20 Jordani si ni àla rẹ̀ ni ìha ìla-õrùn.
Eyi ni ilẹ-iní awọn ọmọ Benjamini, li
àgbegbe rẹ̀ kakiri, gẹgẹ bi idile wọn.
21 Njẹ ilu ẹ̀ya awọn ọmọ Benjamini
gẹgẹ bi idile wọn, ni Jeriko, ati Beti-hogla,
ati Emekikesisi ;
22 Ati Bet-araba, ati Samaraimu, ati
Beteli ;
23 Ati Affimu, ati Para, ati Ofra ;
24 Ati Kefari-ammoni, ati Ofni, ati
Geba ; ilu mejila pẹlu ileto wọn :
25 Gibeoni, ati Rama, ati Beerotu ;
26 Ati Mispe, ati Kefira, ati Mosa ;
27 Ati Rekemu, ati Irpeeli, ati Tarala ;
28 Ati Sela, Elefu, ati Jebusi (ti işe
Jerusalemu), Gibeati, ati Kiriati ; ilu
mẹrinla pẹlu ileto wọn. Eyi ni ilẹ-iní
awọn ọmọ Benjamini gẹgẹ bi idile wọn.

## ORI 19.

IPÍN keji yọ fun Simeoni, ani fun ẹ̀ya
awọn ọmọ Simeoni gẹgẹ bi idile wọn ;
ilẹ-iní wọn si wà lãrin ilẹ-iní awọn ọmọ
Juda.
2 Nwọn si ní Beeri-şeba, tabi Şeba, ati
Molada, ni ilẹ-iní wọn ;
3 Ati Hasari-şuali, ati Bala, ati Esemu ;
4 Ati Eltoladi, ati Bẹtulu, ati Horma ;
5 Ati Siklagi, ati Beti-markabotu, ati
Hasari-susa ;
6 Ati Beti-lebaotu, ati Şaruheni ; ilu
mẹtala pẹlu ileto wọn :
7 Aini, Rimmoni, ati Eteri, ati Aşani ;
ilu mẹrin pẹlu ileto wọn :
8 Ati gbogbo ileto ti o yi ilu wọnyi ká
dé Baalati-beeri, Rama ti Gusù. Eyi ni
ilẹ-iní ẹ̀ya awọn ọmọ Simeoni gẹgẹ bi idile
wọn.
9 Ninu ipín awọn ọmọ Juda ni awọn
ọmọ Simeoni ni ilẹ-iní : nitori ipín awọn
ọmọ Juda pọ̀ju fun wọn : nitorina ni awọn
ọmọ Simeoni fi ní ilẹ-iní lãrin ilẹ-iní wọn.
10 Ilẹ kẹta yọ fun awọn ọmọ Sebuluni
gẹgẹ bi idile wọn : àla ilẹ-iní wọn si dé
Saridi :
11 Àla wọn gòke lọ si ìha ìwọ-õrùn, ani
titi o fi dé Marala, o si dé Dabaşeti ; o si
dé odò ti mbẹ niwaju Jokneamu ;
12 O si şẹri lati Saridi lọ ni ìha ìla-õrùn
si ìla-õrùn dé àla Kisloti-tabori ; o si yọ si
Daberati ; o si jade lọ si Jafia ;
13 Ati lati ibẹ̀ o kọja ni ìha ìla-õrùn si
Gati-heferi, dé Ẹti-kasini ; o si yọ si Rim-
moni titi o fi dé Nea ;
14 Àla na si yi i ká ni ìha ariwa dé
Hannatoni : o si yọ si afonifoji Ifta-eli ;
15 Ati Katati, ati Nahalali, ati Şimroni,
ati Idala, ati Beti-lehemu : ilu mejila pẹlu
ileto wọn.
16 Eyi ni ilẹ-iní awọn ọmọ Sebuluni
gẹgẹ bi idile wọn, ilu wọnyi pẹlu ileto
wọn.
17 Ipín kẹrin yọ fun Issakari, ani fun
awọn ọmọ Issakari gẹgẹ bi idile wọn.
18 Àla wọn si dé Jesreeli, ati Kesuloti,
ati Şunemu ;
19 Ati Hafaraimu, ati Şihoni, ati
Anaharati ;
20 Ati Rabbiti, Kişioni, ati Ebesi ;
21 Ati Remeti, ati Eni-gannimu, ati
Enhadda, ati Beti-passesi ;
22 Àla na si dé Tabori, ati Şahasuma,
ati Beti-şemeşi ; àla wọn yọ si Jordani : ilu
mẹrindilogun pẹlu ileto wọn.
23 Eyi ni ilẹ-iní ẹ̀ya awọn ọmọ Issakari
gẹgẹ bi idile wọn, ilu wọnyi ati ileto wọn.
24 Ipín karun yọ fun ẹ̀ya awọn ọmọ
Aşeri gẹgẹ bi idile wọn.
25 Àla wọn si ni Helkati, ati Hali, ati
Beteni, ati Akşafu ;
26 Ati Allammeleki, ati Amadi, ati
Mişali ; o si dé Karmeli ni ìha ìwọ-õrùn,
ati Şihorilibnati ;
27 O si şẹri lọ si ìha ìla-õrùn dé Beti-
dagoni, o si dé Sebuluni, ati afonifoji Ifta-
eli ni ìha ariwa de Betemeki, ati Neieli ; o
si yọ si Kabulu li apa òsi,
28 Ati Ebroni, ati Rehobu, ati Hammoni,
ati Kana, ani titi dé Sidoni nla ;
29 Àla na si şẹri lọ si Rama, ati si Tire
ilu olodi ; àla na si şẹri lọ si Hosa : o si
yọ si okun ni ìha Aksibu :
30 Ati Umma, ati Afeki, ati Rehobu :
ilu mejilelogun pẹlu ileto wọn.
31 Eyi ni ilẹ-iní ẹ̀ya awọn ọmọ Aşeri
gẹgẹ bi idile wọn, ilu wọnyi pẹlu ileto
wọn.
32 Ipín kẹfa yọ fun awọn ọmọ Naftali,



Digitized by Google

ani fun awọn ọmọ Naftali gẹgẹ bi idile
wọn.
33 Àla wọn si bẹ̀rẹ lati Helefu, lati igi-
oaku Saanannimu, ati Adami-nekebu, ati
Jabneeli dé Lakkumu; o si yọ si Jordani.
34 Àla na si ṣẹri lọ sí ìha ìwọ-õrùn si
Asnoti-taboru, o si ti ibẹ̀ lọ si Hukkoki;
o si dé Sebuluni ni gusù, o si dé Aṣeri ni
ìwọ-õrùn, ati Juda ni Jordani ni ìha ìla-
õrùn.
35 Awọn ilu olodi si ni Siddimu, Seri,
ati Hammati, Rakkati, ati Kinnereti;
36 Ati Adama, ati Rama, ati Hasoru;
37 Ati Kedeṣi, ati Edrei, ati Eni-hasoru;
38 Ati Ironi, ati Migdali-eli, Horemu,
ati Beti-anati, ati Beti-ṣemeṣi; ilu mọkan-
dilogun pẹlu ileto wọn.
39 Eyi ni ilẹ-iní ẹ̀ya awọn ọmọ Naftali
gẹgẹ bi idile wọn, ilu wọnyi pẹlu ileto
wọn.
40 Ilẹ keje yọ fun ẹ̀ya awọn ọmọ Dani
gẹgẹ bi idile wọn.
41 Àla ilẹ-iní wọn si ni Sora, ati Eṣtaolu,
ati Iri-ṣemeṣi;
42 Ati Ṣaalabbini, ati Aijaloni, ati Itla;
43 Ati Eloni, ati Timma, ati Ekroni;
44 Ati Elteke, ati Gibbetoni, ati Ba-
alati;
45 Ati Jehudi, ati Bene-beraki, ati Gati-
rimmọni;
46 Ati Me-jarkoni, ati Rakkoni, pẹlu
àla ti mbẹ kọjusi Jọppa.
47 Awọn ọmọ Dani si gbọ̀n àla wọn lọ:
awọn ọmọ Dani si gòke lọ ibá Leṣemu jà,
nwọn si kó o, nwọn si fi oju idà kọlù u,
nwọn si gbà a, nwọn si ngbé inu rẹ̀, nwọn
si pè Leṣemu ni Dani, gẹgẹ bi orukọ Dani
baba wọn.
48 Eyi ni ilẹ-iní ẹ̀ya ọmọ Dani gẹgẹ bi
idile wọn, ilu wọnyi pẹlu ileto wọn.
49 Nwọn si pari pipín ilẹ na fun ilẹ-iní
gẹgẹ bi àla rẹ̀; awọn ọmọ Israeli si fi ilẹ-
iní kan fun Joṣua ọmọ Nuni lãrin wọn:
50 Gẹgẹ bi aṣẹ OLUWA, nwọn fun u ni
ilu ti o bère, ani Timnati-sera li òke Efra-
imu: o si kọ ilu na, o si ngbé inu rẹ̀.
51 Wọnyi ni ilẹ-iní ti Eleasari alufa,
ati Joṣua ọmọ Nuni, ati awọn olori awọn
baba ẹ̀ya awọn ọmọ Israeli fi keké pín ni
ilẹ-iní ni Ṣilo niwaju OLUWA li ẹnu-ọ̀na
agọ ajọ. Bẹ̃ni nwọn pari pipín ilẹ na.

## ORI 20.

OLUWA si sọ fun Joṣua pe,
2 Wi fun awọn ọmọ Israeli pe, Ẹ yàn
ilu àbo fun ara nyin, ti mo ti sọ fun nyin
lati ọwọ́ Mose wa:
3 Ki apania ti o ba ṣeṣì pa ẹnikan li
aimọ̀ ki o le salọ sibẹ̀: nwọn o si jẹ́ àbo
fun nyin lọwọ olugbẹsan ẹ̀jẹ.
4 On o si salọ si ọkan ninu ilu wọnni,
yio si duro li ẹnu-ọ̀na ibode ilu na, yio si
rò ẹjọ́ rẹ̀ li etí awọn àgba ilu na, nwọn o si
gbà a sọdọ sinu ilu na, nwọn o si fun u ni
ibi kan, ki o le ma bá wọn gbé.
5 Bi olugbẹsan ẹ̀jẹ ba lepa rẹ̀, njẹ ki
nwọn ki o má ṣe fi apania na lé e lọwọ;
nitoriti o pa aladugbo rẹ̀ li aimọ̀, ti kò si
korira rẹ̀ tẹlẹri.
6 On o si ma gbé inu ilu na, titi yio fi
duro niwaju ijọ fun idajọ, titi ikú olori
alufa ti o wà li ọjọ́ wọnni: nigbana ni
apania na yio pada, on o si wá si ilu rẹ̀,
ati si ile rẹ̀, si ilu na lati ibiti o gbé ti
salọ.
7 Nwọn si yàn Kedeṣi ni Galili ni ilẹ
òke Naftali, ati Ṣekemu ni ilẹ òke Efraimu,
ati Kiriati-arba (ti iṣe Hebroni) ni ilẹ òke
Juda.
8 Ati ni ìha keji Jordani lẹba Jeriko ni
ìla-õrùn, nwọn yàn Beseri li aginjù ni
pẹtẹlẹ̀ ninu ẹ̀ya Reubeni, ati Ramotu ni
Gileadi ninu ẹ̀ya Gadi, ati Golani ni Baṣani
ninu ẹ̀ya Manasse.
9 Wọnyi ni awọn ilu ti a yàn fun gbo-
gbo awọn ọmọ Israeli, ati fun alejò ti nṣe
atipo lãrin wọn, ki ẹnikẹni ti o ba ṣeṣì pa
ẹnikan, ki o le salọ sibẹ̀, ki o má ba si ti
ọwọ́ olugbẹsan ẹ̀jẹ ku, titi on o fi duro
niwaju ijọ.

## ORI 21.

NIGBANA ni awọn olori awọn baba
awọn ọmọ Lefi sunmọ Eleasari alufa,
ati Joṣua ọmọ Nuni, ati awọn olori awọn
baba ẹ̀ya awọn ọmọ Israeli;
2 Nwọn si wi fun wọn ni Ṣilo ni ilẹ
Kenaani pe, OLUWA palaṣẹ lati ọwọ́ Mose
wá lati fun wa ni ilu lati ma gbé, ati
àgbegbe wọn fun ohunọ̀sin wa.
3 Awọn ọmọ Israeli si fi ilu wọnyi pẹlu
àgbegbe wọn fun awọn ọmọ Lefi ninu ilẹ-
iní wọn, nipa aṣẹ OLUWA.
4 Ipín si yọ fun idile awọn ọmọ Kohati:
ati awọn ọmọ Aaroni alufa, ti mbẹ ninu
awọn ọmọ Lefi, fi keké gbà ilu mẹtala, lati
inu ẹ̀ya Juda, ati lati inu ẹ̀ya Simeoni, ati
lati inu ẹ̀ya Benjamini.
5 Awọn ti o kù ninu awọn ọmọ Kohati,
fi keké gbà ilu mẹwa lati inu idile ẹ̀ya

Digitized by Google

Efraimu, ati lati inu ẹ̀ya Dani, ati lati inu
àbọ ẹ̀ya Manasse.
6 Awọn ọmọ Gerṣoni si fi keké gbà ilu
mẹtala, lati inu idile ẹ̀ya Issakari, ati ninu
ẹ̀ya Aṣeri, ati lati inu ẹ̀ya Naftali, ati inu
àbọ ẹ̀ya Manasse ni Baṣani.
7 Awọn ọmọ Merari gẹgẹ bi idile wọn,
ní ilu mejila, lati inu ẹ̀ya Reubeni, ati
inu ẹ̀ya Gadi, ati lati inu ẹ̀ya Sebuluni.
8 Awọn ọmọ Israeli fi keké fun awọn
ọmọ Lefi ni ilu wọnyi pẹlu àgbegbe wọn,
gẹgẹ bi OLUWA ti palaṣẹ lati ọwọ́ Mose
wá.
9 Nwọn si fi ilu ti a darukọ wọnyi fun
wọn, lati inu ẹ̀ya awọn ọmọ Juda, ati lati
inu ẹ̀ya awọn ọmọ Simeoni wá:
10 Nwọn si jẹ́ ti awọn ọmọ Aaroni, ni
idile awọn ọmọ Kohati, ti mbẹ ninu awọn
ọmọ Lefi, nitoriti nwọn ní ipín ikini.
11 Nwọn si fi Kiriati-arba, ti iṣe Hebroni
fun wọn, (Arba ni baba Anaki ni ilẹ òke
Juda,) pẹlu àgbegbe rẹ̀ yi i kakiri.
12 Ṣugbọn pápa ilu na, ati ileto rẹ̀, ni
nwọn fi fun Kalebu ọmọ Jefunne ni ilẹ-
iní rẹ̀.
13 Nwọn si fi Hebroni ilu àbo fun apania
pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Libna pẹlu àgbegbe
rẹ̀, fun awọn ọmọ Aaroni alufa;
14 Ati Jatiri pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Eṣte-
moa pẹlu àgbegbe rẹ̀;
15 Ati Holoni pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Debiri
pẹlu àgbegbe rẹ̀;
16 Ati Aini pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Jutta
pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Beti-ṣemeṣi pẹlu àgbe-
gbe rẹ̀; ilu mẹsan ninu awọn ẹ̀ya meji
wọnni.
17 Ati lati inu ẹ̀ya Benjamini, Gibeoni
pẹlu àgbegbe rẹ̀, Geba pẹlu àgbegbe rẹ̀;
18 Anatotu pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Almoni
pelu àgbegbe rẹ̀; ilu mẹrin.
19 Gbogbo ilu awọn ọmọ Aaroni, awọn
alufa, jẹ́ ilu mẹtala pẹlu àgbegbe wọn.
20 Ati idile awọn ọmọ Kohati, awọn
ọmọ Lefi, ani awọn ọmọ Kohati ti o kù,
nwọn ní ilu ti iṣe ipín wọn lati inu ẹ̀ya
Efraimu.
21 Nwọn si fi Ṣekemu fun wọn pẹlu
àgbegbe rẹ̀, ni ilẹ òke Efraimu, ilu àbo fun
apania, ati Geseri pẹlu àgbegbe rẹ̀;
22 Ati Kibsaimu pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati
Beti-horoni pẹlu àgbegbe rẹ̀; ilu mẹrin.
23 Ati ninu ẹ̀ya Dani, Elteke pẹlu àgbe-
gbe rẹ̀, Gibbetoni pẹlu àgbegbe rẹ̀;
24 Aijaloni pẹlu àgbegbe rẹ̀, Gati-
rimmoni pẹlu àgbegbe rẹ̀; ilu mẹrin.
25 Ati ninu àbọ ẹ̀ya Manasṣe, Taanaki
pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Gati-rimmoni pẹlu
àgbegbe rẹ̀; ilu meji.
26 Gbogbo ilu na jasi mẹwa pẹlu àgbe-
gbe wọn fun idile awọn ọmọ Kohati ti
o kù.
27 Ati awọn ọmọ Gerṣoni, idile awọn
ọmọ Lefi, ni nwọn fi Golani ni Baṣani fun
pẹlu àgbegbe rẹ̀, ilu àbo fun apania; lati
inu ẹ̀ya Manasse, ati Be-eṣtera pẹlu àgbe-
gbe rẹ̀; ilu meji.
28 Ati ninu ẹ̀ya Issakari, Kiṣioni pẹlu
àgbegbe rẹ̀, Dabarati pẹlu àgbegbe rẹ̀;
29 Jarmutu pẹlu àgbegbe rẹ̀, Engannimu
pẹlu àgbegbe rẹ̀; ilu mẹrin.
30 Ati ninu ẹ̀ya Aṣeri, Miṣali pẹlu àgbe-
gbe rẹ̀, Abdoni pẹlu àgbegbe rẹ̀;
31 Helkati pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Rehobu
pẹlu àgbegbe rẹ̀; ilu mẹrin.
32 Ati lati inu ẹ̀ya Naftali, Kedeṣi ni
Galili pẹlu àgbegbe rẹ̀, ilu àbo fun apania;
ati Hammotu-dori pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati
Kartani pẹlu àgbegbe rẹ̀; ilu mẹta.
33 Gbogbo ilu awọn ọmọ Gerṣoni gẹgẹ
bi idile wọn, jẹ́ ilu mẹtala pẹlu ileto
wọn.
34 Ati fun idile awọn ọmọ Merari, awọn
ọmọ Lefi ti o kù, ni Jokneamu pẹlu àgbe-
gbe rẹ̀, ati Karta pẹlu àgbegbe rẹ̀, lati inu
ẹ̀ya Sebuluni,
35 Dimna pẹlu àgbegbe rẹ̀, Nahalali pẹlu
àgbegbe rẹ̀; ilu mẹrin.
36 Ati ninu ẹ̀ya Reubeni, Beseri pẹlu
àgbegbe rẹ̀, ati Jahasi pẹlu àgbegbe rẹ̀.
37 Kedemotu pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Mefa-
ati pẹlu àgbegbe rẹ̀; ilu mẹrin.
38 Ati ninu ẹ̀ya Gadi, Ramotu ni Gileadi
pẹlu àgbegbe rẹ̀, ilu àbo fun apania; ati
Mahanaimu pẹlu àgbegbe rẹ̀.
39 Heṣboni pẹlu àgbegbe rẹ̀, Jaseri pẹlu
àgbegbe rẹ̀; ilu mẹrin ni gbogbo rẹ̀.
40 Gbogbo wọnyi ni ilu awọn ọmọ Me-
rari, gẹgẹ bi idile wọn, ani awọn ti o kù
ni idile awọn ọmọ Lefi; ipín wọn si jẹ́ ilu
mejila.
41 Gbogbo ilu awọn ọmọ Lefi ti mbẹ
lãrin ilẹ-iní awọn ọmọ Israeli jẹ́ ilu mejidi-
lãdọta pẹlu àgbegbe wọn.
42 Olukuluku ilu wọnyi li o ní àgbe-
gbe wọn yi wọn ká: bayi ni gbogbo ilu
wọnyi ri.
43 OLUWA si fun Israeli ni gbogbo ilẹ
na, ti o bura lati fi fun awọn baba wọn;
nwọn si gbà a, nwọn si ngbé inu rẹ̀.
44 OLUWA si fun wọn ni isimi yiká kiri,
gẹgẹ bi gbogbo eyiti o bura fun awọn baba
wọn: kò si sí ọkọnrin kan ninu gbogbo

Digitized by Google

awọn ọtá wọn ti o duro niwaju wọn; OLUWA
fi gbogbo awọn ọtá wọn lé wọn lọwọ.
45 Ohunkohun kò tàse ninu ohun rere
ti OLUWA ti sọ fun ile Israeli: gbogbo rẹ̀
li o ṣẹ.

ORI 22.

NIGBANA ni Joṣua pè awọn ọmọ Reubeni, ati awọn ọmọ Gadi, ati àbọ ẹ̀ya
Manasse,
2 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin ti ṣe gbogbo eyiti Mose iranṣẹ OLUWA palaṣẹ fun
nyin, ẹnyin si gbọ́ ohùn mi ni gbogbo eyiti
mo palaṣẹ fun nyin:
3 Ẹnyin kò fi awọn arakọnrin nyin silẹ
lati ọjọ́ pipọ̀ wọnyi wá titi o fi di oni, ṣugbọn ẹnyin ṣe afiyesi ilọ ofin OLUWA Ọlọrun
nyin.
4 Njẹ nisisiyi OLUWA Ọlọrun nyin ti fi
isimi fun awọn arakọnrin nyin, gẹgẹ bi o ti
sọ fun wọn: njẹ nisisiyi ẹ pada, ki ẹ si lọ
sinu agọ́ nyin, ati si ilẹ-iní nyin, ti Mose
iranṣẹ OLUWA ti fun nyin ni ìha keji
Jordani.
5 Kìki ki ẹ kiyesara gidigidi lati pa aṣẹ
ati ofin mọ́, ti Mose iranṣẹ OLUWA fi fun
nyin, lati fẹ́ OLUWA Ọlọrun nyin, ati lati
ma rìn ni gbogbo ọ̀na rẹ̀, ati lati ma pa aṣẹ
rẹ̀ mọ́, ati lati faramọ́ ọ, ati lati sìn i
pẹlu àiya nyin gbogbo ati pẹlu ọkàn nyin
gbogbo.
6 Bẹ̃ni Joṣua sure fun wọn, o si rán wọn
lọ: nwọn si lọ sinu agọ́ wọn.
7 Njẹ fun àbọ ẹ̀ya Manasse ni Mose ti fi
ilẹ-iní wọn fun ni Baṣani: ṣugbọn fun àbọ
ẹ̀ya ti o kù ni Joṣua fi ilẹ-iní fun pẹlu awọn
arakọnrin wọn ni ìha ihin Jordani ni ìwọ-õrùn. Nigbati Joṣua si rán wọn pada lọ
sinu agọ́ wọn, o sure fun wọn pẹlu,
8 O si wi fun wọn pe, Ẹ pada lọ pẹlu ọrọ̀
pipọ̀ si agọ́ nyin, ati pẹlu ohunọ̀sin pipọ̀,
pẹlu fadakà, ati pẹlu wurà, ati pẹlu idẹ,
ati pẹlu irin, ati pẹlu aṣọ pipọ̀pipọ: ẹ bá
awọn arakọnrin nyin pín ikogun awọn ọtá
nyin.
9 Awọn ọmọ Reubeni, ati awọn ọmọ
Gadi, ati àbọ ẹ̀ya Manasse si pada, nwọn si
lọ kuro lọdọ awọn ọmọ Israeli lati Ṣilo, ti
mbẹ ni ilẹ Kenaani, lati lọ si ilẹ Gileadi, si
ilẹ iní wọn, eyiti nwọn ti gbà, gẹgẹ bi aṣẹ
OLUWA lati ọwọ́ Mose wá.
10 Nigbati nwọn si dé eti Jordani, ti
mbẹ ni ilẹ Kenaani, awọn ọmọ Reubeni, ati
awọn ọmọ Gadi, ati àbọ ẹ̀ya Manasse mọ
pẹpẹ kan lẹba Jordani, pẹpẹ ti o tobi lati
wò.
11 Awọn ọmọ Israeli si gbọ́ pe, Kiyesi i,
awọn ọmọ Reubeni, ati awọn ọmọ Gadi, ati
àbọ ẹ̀ya Manasse mọ pẹpẹ kan dojukọ ilẹ
Kenaani, lẹba Jordani ni ìha keji awọn ọmọ
Israeli.
12 Nigbati awọn ọmọ Israeli gbọ́ ọ, gbogbo ijọ awọn ọmọ Israeli kó ara wọn jọ ni
Ṣilo, lati gòke lọ ibá wọn jagun.
13 Awọn ọmọ Israeli si rán Finehasi ọmọ
Eleasari alufa si awọn ọmọ Reubeni, ati si
awọn ọmọ Gadi, ati si àbọ ẹ̀ya Manasse ni
ilẹ Gileadi;
14 Ati awọn olori mẹwa pẹlu rẹ̀, olori ile
baba kọkan fun gbogbo ẹ̀ya Israeli; olukuluku si ni olori ile baba wọn ninu ẹgbẹgbẹrun Israeli.
15 Nwọn si dé ọdọ awọn ọmọ Reubeni,
ati ọdọ awọn ọmọ Gadi, ati ọdọ àbọ ẹ̀ya
Manasse, ni ilẹ Gileadi, nwọn si bá wọn
sọ̀rọ pe,
16 Bayi ni gbogbo ijọ OLUWA wi, Ẹ̀ṣẹ
kili eyiti ẹnyin da si Ọlọrun Israeli, lati
pada li oni kuro lẹhin OLUWA, li eyiti
ẹnyin mọ pẹpẹ kan fun ara nyin, ki ẹnyin
ki o le ṣọ̀tẹ si OLUWA li oni?
17 Ẹ̀ṣẹ ti Peori kò to fun wa kọ́, ti a kò
ti iwẹ̀mọ́ ninu rẹ̀ titi di oni, bi o tilẹ ṣe pe
ajakalẹ-àrun wà ninu ijọ OLUWA,
18 Ti ẹnyin fi pada kuro lẹhin OLUWA
li oni? Yio si ṣe, bi ẹnyin ti ṣọ̀tẹ si OLUWA li oni, li ọla, on o binu si gbogbo ijọ
Israeli.
19 Njẹ bi o ba ṣepe ilẹ iní nyin kò ba
mọ́, ẹ rekọja si ilẹ-iní OLUWA, nibiti agọ́
OLUWA ngbé, ki ẹ si gbà ilẹ-iní lãrin wa:
ṣugbọn ẹnyin máṣe ṣọ̀tẹ si OLUWA, bẹ̃ni ki
ẹ máṣe ṣọ̀tẹ si wa, ni mimọ pẹpẹ miran fun
ara nyin lẹhin pẹpẹ OLUWA Ọlọrun wa.
20 Ṣe bẹ̃ni Akani ọmọ Sera da ẹ̀ṣẹ niti
ohun ìyasọtọ, ti ibinu si dé sori gbogbo ijọ
Israeli? Ọkọnrin na kò nikan ṣegbé ninu
ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
21 Nigbana ni awọn ọmọ Reubeni, ati
awọn ọmọ Gadi, ati àbọ ẹ̀ya Manasse dahùn,
nwọn si wi fun awọn olori ẹgbẹgbẹrun
Israeli pe,
22 OLUWA, Ọlọrun awọn ọlọrun, OLUWA
Ọlọrun awọn ọlọrun, On mọ̀, Israeli pẹlu
yio si mọ̀; bi o ba ṣepe ni ìṣọtẹ ni, tabi bi
ni irekọja si OLUWA, (máṣe gbà wa li oni,)
23 Ni awa fi mọ pẹpẹ fun ara wa, lati
yipada kuro lẹhin OLUWA; tabi bi o ba ṣe
pe lati ru ẹbọ sisun, tabi ẹbọ ohunjijẹ, tabi
ẹbọ alafia lori rẹ̀, ki OLUWA tikala rẹ̀ ki o
bère rẹ̀.
24 Bi o ba ṣepe awa kò kuku ṣe e nitori

Digitized by Google

aniyàn, ati nitori nkan yi pe, Lẹhinọla
awọn ọmọ nyin le wi fun awọn ọmọ wa pe,
Kili o kàn nyin niti OLUWA, Ọlọrun
Israeli?
25 Nitoriti Ọlọrun ti fi Jordani pàla li
agbedemeji awa ati ẹnyin, ẹnyin ọmọ Reu-
beni, ati awọn ọmọ Gadi; ẹnyin kò ní ipín
niti OLUWA: bẹ̃li awọn ọmọ nyin yio mu
ki awọn ọmọ wa ki o dẹkun ati ma bẹ̀ru
OLUWA.
26 Nitorina li a ṣe wipe, Ẹ jẹ ki a mura
nisisiyi lati mọ pẹpẹ kan, ki iṣe fun ẹbọ si-
sun, tabi fun ẹbọ kan:
27 Ṣugbọn ẹrí ni li agbedemeji awa ati
ẹnyin, ati awọn iran wa lẹhin wa, ki awa
ki o le ma fi ẹbọ sisun wa, ati ẹbọ wa, pẹlu
ẹbọ alafia wa jọsìn fun OLUWA niwaju rẹ̀;
ki awọn ọmọ nyin ki o má ba wi fun awọn
ọmọ wa lẹhiñọla pe, Ẹnyin kò ní ipín niti
OLUWA.
28 Nitorina ni awa ṣe wipe, Yio si ṣe,
nigbati nwọn ba wi bẹ̃ fun wa, tabi fun
awọn iran wa lẹhinọla, awa o si wipe, Ẹ wò
ẹrẹ pẹpẹ OLUWA, ti awọn baba wa mọ, ki
iṣe fun ẹbọ sisun, bẹ̃ni ki iṣe fun ẹbọ; ṣu-
gbọn o jasi ẹrí li agbedemeji awa ati ẹnyin.
29 Ki Ọlọrun má jẹ ki awa ki o ṣọ̀tẹ si
OLUWA, ki awa si pada li oni kuro lẹhin
OLUWA, lati mọ pẹpẹ fun ẹbọ sisun, fun
ẹbọ ohunjijẹ, tabi fun ẹbọ kan, lẹhin pẹpẹ
OLUWA Ọlọrun wa ti mbẹ niwaju agọ́ rẹ̀.
30 Nigbati Finehasi alufa, ati awọn olori
ijọ ati awọn olori ẹgbẹgbẹrun Israeli ti o
wà pẹlu rẹ̀, gbọ́ ọ̀rọ ti awọn ọmọ Reubeni,
ati awọn ọmọ Gadi, ati awọn ọmọ Manasse
sọ, o dùn mọ́ wọn.
31 Finehasi ọmọ Eleasari alufa si wi fun
awọn ọmọ Reubeni, ati fun awọn ọmọ Gadi,
ati fun awọn ọmọ Manasse pe, Li oni li
awa mọ̀ pe OLUWA wà lãrin wa, nitoriti
ẹnyin kò dẹṣẹ yi si OLUWA: nisisiyi ẹnyin
yọ awọn ọmọ Israeli kuro lọwọ OLUWA.
32 Finehasi ọmọ Eleasari alufa, ati awọn
olori, si pada lati ọdọ awọn ọmọ Reubeni,
ati lati ọdọ awọn ọmọ Gadi, ni ilẹ Gileadi,
si ilẹ Kenaani, sọdọ awọn ọmọ Israeli;
nwọn si mú ìhin pada tọ̀ wọn wá.
33 Ohun na si dùn mọ́ awọn ọmọ Israeli;
awọn ọmọ Israeli si fi ibukún fun Ọlọrun,
nwọn kò si sọ ti ati gòke tọ̀ wọn lọ ijà, lati
run ilẹ na ninu eyiti awọn ọmọ Reubeni ati
awọn ọmọ Gadi ngbé.
34 Awọn ọmọ Reubeni ati awọn ọmọ
Gadi si sọ pẹpẹ na ni Edi: nwọn wipe,
Nitori ẹrí ni li agbedemeji awa ati ẹnyin pe
OLUWA on li Ọlọrun.

## ORI 23.

OSI ṣe li ọjọ́ pipọ̀ lẹhin ti OLUWA ti fi
isimi fun Israeli lọwọ gbogbo awọn
ọtá wọn yiká, ti Joṣua di arugbó, ti o si pọ̀
li ọjọ́;
2 Joṣua si pè gbogbo Israeli, ati awọn
àgba wọn, ati awọn olori wọn, ati awọn
onidajọ wọn, ati awọn ijoye wọn, o si wi
fun wọn pe, Emi di arugbó tán, emi si pọ̀
li ọjọ́:
3 Ẹnyin si ti ri ohun gbogbo ti OLUWA
Ọlọrun nyin ti ṣe si gbogbo orilẹ-ède wọnyi
nitori nyin; nitori OLUWA Ọlọrun nyin,
on li ẹniti o ti jà fun nyin.
4 Wò o, emi ti pín awọn orilẹ-ède wọnyi
ti o kù fun nyin, ni ilẹ-iní fun awọn ẹ̀ya
nyin, lati Jordani lọ, pẹlu gbogbo awọn
orilẹ-ède ti mo ti ke kuro, ani titi dé okun
nla ni ìha ìwọ-õrùn.
5 OLUWA Ọlọrun nyin, on ni yio tì wọn
jade kuro niwaju nyin, yio si lé wọn kuro
li oju nyin; ẹnyin o si ní ilẹ wọn, gẹgẹ bi
OLUWA Ọlọrun nyin ti sọ fun nyin.
6 Nitorina ẹ mura gidigidi lati tọju ati
lati ṣe ohun gbogbo ti a kọ sinu iwé ofin
Mose, ki ẹnyin ki o má ṣe yipada kuro ni-
nu rẹ̀ si ọwọ́ ọtún tabi si ọwọ́ òsi;
7 Ki ẹnyin ki o máṣe wá sãrin awọn
orilẹ-ède wọnyi, awọn wọnyi ti o kù pẹlu
nyin; ki ẹnyin máṣe da orukọ oriṣa wọn,
bẹ̃ni ki ẹ máṣe fi wọn bura, ẹ má ṣe sìn
wọn, bẹ̃ni ki ẹ máṣe tẹriba fun wọn:
8 Ṣugbọn ki ẹnyin faramọ́ OLUWA Ọlọ-
run nyin, gẹgẹ bi ẹnyin ti nṣe titi di oni.
9 Nitoriti OLUWA ti lé awọn orilẹ-ède
nla ati alagbara kuro niwaju nyin; ṣugbọn
bi o ṣe ti nyin ni, kò sí ọkọnrin kan ti o ti
iduro niwaju nyin titi di oni.
10 Ọkọnrin kan ninu nyin yio lé ẹgbẹ-
run: nitoripe OLUWA Ọlọrun nyin, on li
ẹniti njà fun nyin, gẹgẹ bi o ti sọ fun nyin.
11 Nitorina ẹ kiyesara nyin gidigidi, ki
ẹ fẹ́ OLUWA Ọlọrun nyin.
12 Ṣugbọn bi ẹ ba daṣà ati pada, ti ẹ si
faramọ́ iyokù awọn orilẹ-ède wọnyi, ani
awọn wọnyi ti o kù lãrin nyin, ti ẹ si bá
wọn gbeyawo, ti ẹ si nwọle tọ̀ wọn, ti awọn
si nwọle tọ̀ nyin:
13 Ki ẹnyin ki o mọ̀ dajudaju pe OLUWA
Ọlọrun nyin ki yio lé awọn orilẹ-ède wọnyi
jade mọ́ kuro niwaju nyin: ṣugbọn nwọn
o jẹ́ okùn-didẹ ati ẹgẹ́ fun nyin, ati paṣán
ni ìha nyin, ati ẹgún li oju nyin, titi ẹ o fi
ṣegbé kuro ni ilẹ daradara yi ti OLUWA
Ọlọrun nyin ti fi fun nyin.

Digitized by Google

14 Ẹnyin kiyesi i, li oni emi nlọ si ọ̀na
gbogbo aiye: ẹnyin si mọ̀ li àiya nyin gbo-
gbo, ati li ọkàn nyin gbogbo pe, kò sí ohun
kan ti o tase ninu ohun rere gbogbo ti
OLUWA Ọlọrun nyin ti sọ niti nyin; gbo-
gbo rẹ̀ li o ṣẹ fun nyin, kò si sí ohun ti o
tase ninu rẹ̀.
15 Yio si ṣe, gẹgẹ bi ohun rere gbogbo ti
ṣẹ fun nyin, ti OLUWA Ọlọrun nyin ti sọ
fun nyin; bẽni OLUWA yio mú ibi gbogbo
bá nyin, titi yio fi pa nyin run kuro ni ilẹ
daradara yi ti OLUWA Ọlọrun nyin ti fi fun
nyin.
16 Nigbati ẹnyin ba re majẹmu OLUWA
Ọlọrun nyin kọja, ti o palaṣẹ fun nyin, ti ẹ
ba si lọ, ti ẹ ba nsìn oriṣa ti ẹnyin ba tẹ̀
ori nyin bà fun wọn; nigbana ni ibinu
OLUWA yio rú si nyin, ẹnyin o si ṣegbé
kánkan kuro ni ilẹ daradara ti o ti fi fun
nyin.

## ORI 24.

JOṢUA si pè gbogbo awọn ẹ̀ya Israeli jọ
si Ṣekemu, o si pè awọn àgba Israeli,
ati awọn olori wọn, ati awọn onidajọ wọn,
ati awọn ijoye wọn; nwọn si fara wọn hàn
niwaju Ọlọrun.
2 Joṣua si wi fun gbogbo awọn enia pe,
Bayi ni OLUWA, Ọlọrun Israeli wi, Awọn
baba nyin ti gbé ìha keji Odò nì li atijọ rí,
ani Tera, baba Abrahamu, ati baba Nahori:
nwọn si sìn oriṣa.
3 Emi si mú Abrahamu baba nyin lati
ìha keji Odò na wá, mo si ṣe amọ̀na rẹ̀ là
gbogbo ilẹ Kenaani já, mo si sọ irú-ọmọ rẹ̀
di pipọ̀, mo si fun u ni Isaaki.
4 Emi si fun Isaaki ni Jakobu ati Esau:
mo si fun Esau li òke Seiri lati ní i; Jako-
bu pẹlu awọn ọmọ rẹ̀ si sọkalẹ lọ si Egipti.
5 Mo si rán Mose ati Aaroni, mo si yọ
Egipti lẹnu, gẹgẹ bi eyiti mo ṣe lãrin rẹ̀:
lẹhin na mo si mú nyin jade.
6 Emi si mú awọn baba nyin jade kuro
ni Egipti: ẹnyin si dé okun; awọn ara
Egipti si lepa awọn baba nyin ti awọn ti
kẹkẹ́ ati ẹlẹṣin de Okun Pupa.
7 Nigbati nwọn kigbepè OLUWA, o fi
òkunkun si agbedemeji ẹnyin ati awọn ara
Egipti, o si mú okun ya lù wọn, o si bò wọn
mọlẹ; oju nyin si ti ri ohun ti mo ṣe ni
Egipti: ẹnyin si gbé inu aginjù li ọjọ́ pipọ̀.
8 Emi si mú nyin wá si ilẹ awọn Amori,
ti ngbé ìha keji Jordani; nwọn si bá nyin
jà: emi si fi wọn lé nyin lọwọ, ẹnyin si ní
ilẹ wọn; emi si run wọn kuro niwaju nyin.
9 Nigbana ni Balaki ọmọ Sipporu, ọba
Moabu dide, o si ba Israeli jagun; o si
ranṣẹ pè Balaamu ọmọ Beori lati fi nyin bú:
10 Ṣugbọn emi kò fẹ́ fetisi ti Balaamu;
nitorina o nsure fun nyin ṣá: mo si gbà
nyin kuro li ọwọ́ rẹ̀.
11 Ẹnyin si gòke Jordani, ẹ si dé Jeri-
ko: awọn ọkọnrin Jeriko si fi ìja fun nyin,
awọn Amori, ati awọn Perissi, ati awọn ara
Kenaani, ati awọn Hitti, ati awọn Girgaṣi,
awọn Hifi, ati awọn Jebusi; emi si fi wọn
lé nyin lọwọ.
12 Emi si rán agbọ́n siwaju nyin, ti o lé
wọn kuro niwaju nyin, ani awọn ọba Amori
meji; ki iṣe pẹlu idà rẹ, bẽni ki iṣe pẹlu
ọrun rẹ.
13 Emi si fun nyin ni ilẹ ti iwọ kò ṣe
lãla si, ati ilu ti ẹnyin kò tẹ̀dó, ẹnyin si
ngbé inu wọn; ninu ọgbà-àjara ati ọgbà-
igi-olifi ti ẹnyin kò gbìn li ẹnyin njẹ.
14 Njẹ nitorina ẹ bẹru OLUWA, ki ẹ si
ma sìn i li ododo ati li otitọ: ki ẹ si mu
oriṣa wọnni kuro ti awọn baba nyin sin ni
ìha keji Odò nì, ati ni Egipti; ki ẹ si ma
sìn OLUWA.
15 Bi o ba si ṣe buburu li oju nyin lati
sìn OLUWA, ẹ yàn ẹniti ẹnyin o ma sìn li
oni; bi oriṣa wọnni ni ti awọn baba nyin ti
o wà ni ìha keji Odò ti nsìn, tabi awọn
oriṣa awọn Amori, ni ilẹ ẹniti ẹnyin ngbé;
ṣugbọn bi o ṣe ti emi ati ile mi ni, OLUWA
li awa o ma sìn.
16 Awọn enia na dahùn, nwọn si wipe,
Ki a má ri ti awa o fi kọ̀ OLUWA silẹ, lati
sìn oriṣa;
17 Nitori OLUWA Ọlọrun wa, on li ẹniti
o mú wa, ati awọn baba wa gòke lati ilẹ
Egipti wá, kuro li oko-ẹrú, ti o si ṣe iṣẹ-
iyanu nla wọnni li oju wa, ti o si pa wa mọ́
ni gbogbo ọ̀na ti awa rìn, ati lãrin gbogbo
enia ti awa là kọja:
18 OLUWA si lé gbogbo awọn enia na
jade kuro niwaju wa, ani awọn Amori ti
ngbé ilẹ na: nitorina li awa pẹlu o ṣe ma
sìn OLUWA; nitori on li Ọlọrun wa.
19 Joṣua si wi fun awọn enia na pe,
Enyin kò le sìn OLUWA; nitoripe Ọlọrun
mimọ́ li on; Ọlọrun owú li on; ki yio dari
irekọja ati ẹ̀ṣẹ nyin jì nyin.
20 Bi ẹnyin ba kọ̀ OLUWA silẹ, ti ẹ ba si
sìn ọlọrun ajeji, nigbana ni on o pada yio
si ṣe nyin ni ibi, yio si run nyin, lẹhin ti o
ti ṣe nyin li ore tán.
21 Awọn enia na si wi fun Joṣua pe,
Ndao; ṣugbọn OLUWA li awa o sìn.
22 Joṣua si wi fun awọn enia na pe,
Ẹnyin li ẹlẹri si ara nyin pe, ẹnyin yàn

Digitized by Google

OLUWA fun ara nyin, lati ma sìn i. Nwọn si wipe, Awa ṣe ẹlẹri.

23 Njẹ nitorina ẹ mú ọlọrun ajeji ti mbẹ lãrin nyin kuro, ki ẹnyin si yí ọkàn nyin si OLUWA Ọlọrun Israeli.

24 Awọn enia na si wi fun Joṣua pe, OLUWA Ọlọrun wa li awa o ma sìn, ohùn rẹ̀ li awa o sí ma gbọ́.

25 Bẹ̃ni Joṣua bá awọn enia na dá majẹmu li ọjọ́ na, o si fi ofin ati ìlana fun wọn ni Ṣekemu.

26 Joṣua si kọ ọ̀rọ wọnyi sinu iwé ofin Ọlọrun, o si mú okuta nla kan, o si gbé e kà ibẹ̀ labẹ igi-oaku kan, ti o wà ni ibi-mimọ́ OLUWA.

27 Joṣua si wi fun gbogbo awọn enia pe, Ẹ kiyesi i, okuta yi ni ẹlẹri fun wa; nitori o ti gbọ́ gbogbo ọ̀rọ OLUWA ti o bá wa sọ: nitorina yio ṣe ẹlẹri si nyin, ki ẹnyin má ba sẹ́ Ọlọrun nyin.

28 Bẹ̃ni Joṣua jọwọ awọn enia na lọwọ lọ, olukuluku si ilẹ-iní rẹ̀.

29 O si ṣe lẹhin nkan wọnyi, ni Joṣua ọmọ Nuni, iranṣẹ OLUWA kú, o jẹ́ ẹni ãdọfa ọdún.

30 Nwọn si sin i ni àla ilẹ-iní rẹ̀ ni Timnatisera, ti mbẹ ni ilẹ òke Efraimu, ni ìha ariwa òke Gaaṣi.

31 Israeli si sìn OLUWA ni gbogbo ọjọ́ Joṣua, ati ni gbogbo ọjọ́ awọn àgba ti o wà lẹhin Joṣua, ti o si mọ̀ gbogbo iṣẹ OLUWA, ti o ṣe fun Israeli.

32 Egungun Josefu, ti awọn ọmọ Israeli gbé gòke lati Egipti wá, ni nwọn si sin ni Ṣekemu, ni ipín ilẹ ti Jakobu rà lọwọ awọn ọmọ Hamori baba Ṣekemu li ọgọrun owo: o si di ilẹ-iní awọn ọmọ Josefu.

33 Eleasari ọmọ Aaroni si kú; nwọn si sin i li òke Finehasi ọmọ rẹ̀, ti a fi fun u li òke Efraimu.

IWE AWỌN

# ONIDAJỌ.

## ORI 1.

O SI ṣe lẹhin ikú Joṣua, ni awọn ọmọ Israeli bère lọdọ OLUWA wipe, Tani yio tète gòke tọ̀ awọn ara Kenaani lọ fun wa, lati bá wọn jà?

2 OLUWA si wipe, Juda ni yio gòke lọ: kiyesi i, emi fi ilẹ na lé e lọwọ.

3 Juda si wi fun Simeoni arakọnrin rẹ̀ pe, Bá mi gòke lọ si ilẹ mi, ki awa ki o le bá awọn ara Kenaani jà; emi na pẹlu yio si bá ọ lọ si ilẹ rẹ. Simeoni si bá a lọ.

4 Juda si gòke lọ; OLUWA si fi awọn ara Kenaani ati awọn Perissi lé wọn lọwọ: nwọn si pa ẹgbarun ọkọnrin ninu wọn ni Beseki.

5 Nwọn si ri Adoni-beseki ni Beseki: nwọn si bá a jà, nwọn si pa awọn ara Kenaani ati awọn Perissi.

6 Ṣugbọn Adoni-beseki sá; nwọn si lepa rẹ̀, nwọn si mú u, nwọn si ke àtampako ọwọ́ rẹ̀, ati ti ẹsẹ̀ rẹ̀.

7 Adoni-beseki si wipe, Ãdọrin ọba li emi ke li àtampako ọwọ́ wọn ati ti ẹsẹ̀ wọn, ti nwọn nṣà onjẹ wọn labẹ tabeli mi: gẹgẹ bi emi ti ṣe, bẹ̃li Ọlọrun si san a fun mi. Nwọn si mú u wá si Jerusalemu, o si kú sibẹ̀.

8 Awọn ọmọ Juda si bá Jerusalemu jà, nwọn si kó o, nwọn si fi oju idà kọlù u, nwọn si tinabọ ilu na.

9 Lẹhin na awọn ọmọ Juda si sọkalẹ lọ lati bá awọn ara Kenaani jà, ti ngbé ilẹ òke, ati ni Gusù, ati ni afonifoji nì.

10 Juda si tọ̀ awọn ara Kenaani ti ngbé Hebroni lọ: (orukọ Hebroni ni ìgba iṣaju si ni Kiriati-arba:) nwọn si pa Ṣeṣai, ati Ahimani ati Talmai.

11 Lati ibẹ̀ o si gbé ogun tọ̀ awọn ara Debiri lọ. (Orukọ Debiri ni ìgba atijọ si ni Kiriati-seferi.)

12 Kalebu si wipe, Ẹniti o ba kọlù Kiriati-seferi, ti o si kó o, on li emi o fi Aksa ọmọbirin mi fun li aya.

13 Otnieli ọmọ Kenasi, aburó Kalebu, si kó o: o si fi Aksa ọmọbirin rẹ̀ fun u li aya.

Digitized by Google

14 O si ṣe, nigbati Aksa dé ọdọ rẹ̀, o si
rọ̀ ọ lati bère oko kan lọdọ baba rẹ̀: Aksa
si sọkalẹ kuro lori kẹtẹkẹtẹ rẹ̀; Kalebu si
wi fun u pe, Kini iwọ nfẹ̀?
15 On si wi fun u pe, Ta mi lọrẹ kan;
nitoriti iwọ ti fun mi ni ilẹ Gusù, fi isun
omi fun mi pẹlu. Kalebu si fi isun òke ati
isun isalẹ fun u.
16 Awọn ọmọ Keni, ana Mose, si bá
awọn ọmọ Juda gòke lati ilu ọpẹ lọ si agin-
jù Juda, ni gusù Aradi; nwọn si lọ, nwọn
si mbá awọn enia na gbé.
17 Juda si bá Simeoni arakọnrin rẹ̀ lọ,
nwọn si pa awọn ara Kenaani ti ngbé Sefati,
nwọn si pa a run patapata. A si pè orukọ
ilu na ni Horma.
18 Juda si kó Gasa pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati
Aṣkeloni pẹlu àgbegbe rẹ̀, ati Ekroni pẹlu
àgbegbe rẹ̀.
19 OLUWA si wà pẹlu Juda; o si gbà ilẹ
òke; nitori on kò le lé awọn enia ti o wà
ni pẹtẹlẹ̀ jade, nitoriti nwọn ní kẹkẹ́ irin.
20 Nwọn si fi Hebroni fun Kalebu, gẹgẹ
bi Mose ti wi: on si lé awọn ọmọ Anaki
mẹtẹta jade kuro nibẹ̀.
21 Awọn ọmọ Benjamini kò si lé awọn
Jebusi ti ngbé Jerusalemu jade; ṣugbọn
awọn Jebusi mbá awọn ọmọ Benjamini gbé
ni Jerusalemu titi di oni.
22 Ati awọn ara ile Josefu, awọn pẹlu
si gòke lọ bá Beti-eli jà: OLUWA si wá
pẹlu wọn.
23 Awọn ara ile Josefu rán amí lọ si
Beti-eli. (Orukọ ilu na ni ìgba atijọ rí si
ni Lusi.)
24 Awọn amí na si ri ọkọnrin kan ti
o ti inu ilu na jade wá, nwọn si wi fun u
pe, Awa bẹ̀ ọ, fi ọ̀na atiwọ̀ ilu yi hàn wa,
awa o si ṣãnu fun ọ.
25 O si fi ọ̀na atiwọ̀ ilu na hàn wọn,
nwọn si fi oju idà kọlù ilu na; ṣugbọn
nwọn jọwọ ọkọnrin na ati gbogbo awọn
ara ile rẹ̀ lọwọ lọ.
26 Okọnrin na si lọ si ilẹ awọn Hitti, o
si tẹ̀-ilu kan dó, o si pè orukọ rẹ̀ ni Lusi:
eyi si li orukọ rẹ̀ titi di oni.
27 Manasse kò si lé awọn ara Betiseani
ati ilu rẹ̀ wọnni jade, tabi awọn ara
Taanaki ati ilu rẹ̀ wọnni, tabi awọn ara
Dori ati ilu rẹ̀ wọnni, tabi awọn ara
Ibleamu ati ilu rẹ̀ wọnni, tabi awọn ara
Megiddo ati ilu rẹ̀ wọnni: ṣugbọn awọn
ara Kenaani ngbé ilẹ na.
28 O si ṣe, nigbati Israeli di alagbara
tan, nwọn si mu awọn ara Kenaani sìn,
nwọn kò si lé wọn jade patapata.
29 Efraimu kò si lé awọn ara Kenaani ti
ngbé Geseri jade; ṣugbọn awọn ara Ke-
naani ngbé ãrin wọn ni Geseri.
30 Sebuluni kò lé awọn ara Kitroni jade,
tabi awọn ara Nahalolu; ṣugbọn awọn ara
Kenaani ngbé ãrin wọn, nwọn si nsìn.
31 Aṣeri kò lé awọn ara Akko jade, tabi
awọn ara Sidoni, tabi awọn ara Alabu, tabi
awọn ara Aksibu, tabi awọn ara Helba, tabi
awọn ara Afiki, tabi awọn ara Rehobu:
32 Ṣugbọn awọn ọmọ Aṣeri ngbé ãrin
awọn ara Kenaani, ti ngbé ilẹ na: nitoriti
nwọn kò lé wọn jade.
33 Naftali kò lé awọn ara Beti-ṣemeṣi
jade, tabi awọn ara Beti-anati; ṣugbọn on
ngbé ãrin awọn ara Kenaani, ti ngbé ilẹ
na: ṣugbọn awọn ara Beti-ṣemeṣi ati Beti-
anati di ẹniti nsìn wọn.
34 Awọn Amori si fi agbara ti awọn ọmọ
Dani sori òke: nitoripe nwọn kò jẹ ki
nwọn ki o sọkalẹ wá si afonifoji.
35 Awọn Amori si ngbé òke Heresi, ni
Aijaloni, ati ni Ṣaalbimu: ọwọ́ awọn ara
ile Josefu bori, nwọn si di ẹniti nsìn.
36 Àla awọn Amori si ni lati ìgoke lọ si
Akrabbimu, lati ibi apata lọ si òke.

## ORI 2.

ANGELI OLUWA si ti Gilgali gòke wá
si Bokimu. O si wipe, Emi mu nyin
gòke lati Egipti wá, emi si mú nyin wá si
ilẹ ti emi ti bura fun awọn baba nyin;
emi si wipe, Emi ki yio dà majẹmu mi
pẹlu nyin lailai:
2 Ẹnyin kò si gbọdọ bá awọn ara ilẹ yi
dá majemu; ẹnyin o wó pẹpẹ wọn lulẹ:
ṣugbọn ẹnyin kò gbọ́ ohùn mi: Ẽha ti ṣe
ti ẹnyin fi ṣe yi?
3 Nitorina emi pẹlu wipe, Emi ki yio lé
wọn jade kuro niwaju nyin; ṣugbọn nwọn
o jẹ́ ẹgún ni ìha nyin, ati awọn oriṣa wọn
yio di ikẹkun fun nyin.
4 O si ṣe, nigbati angeli OLUWA sọ ọ̀rọ
wọnyi fun gbogbo awọn ọmọ Israeli, awọn
enia na si gbé ohùn wọn soke, nwọn si
sọkun.
5 Nwọn si pè orukọ ibẹ̀ na ni Bokimu:
nwọn si ru ẹbọ nibẹ̀ si OLUWA.
6 Nigbati Joṣua si ti jọwọ awọn enia
lọwọ lọ, olukuluku awọn ọmọ Israeli si lọ
sinu ilẹ-iní rẹ̀ lati gbà ilẹ na.
7 Awọn enia na si sìn OLUWA ni gbogbo
ọjọ́ Joṣua, ati ni gbogbo ọjọ́ awọn àgba ti o
wà lẹhin Joṣua, awọn ẹniti o ri gbogbo iṣẹ
nla OLUWA, ti o ṣe fun Israeli.

Digitized by Google

8 Joṣua ọmọ Nuni, iranṣẹ OLUWA si kú, nigbati o di ẹni ãdọfa ọdún.

9 Nwọn si sinkú rẹ̀ li àla ilẹ-iní rẹ̀ ni Timnati-heresi, ni ilẹ òke Efraimu, li ariwa oke Gaaṣi.

10 Ati pẹlu a si kó gbogbo iran na jọ sọdọ awọn baba wọn: iran miran si hù lẹhin wọn, ti kò mọ̀ OLUWA, tabi iṣẹ ti o ṣe fun Israeli.

11 Awọn ọmọ Israeli si ṣe buburu niwaju OLUWA, nwọn si nsìn Baalimu:

12 Nwọn si kọ̀ OLUWA, Ọlọrun awọn baba wọn silẹ, ti o mú wọn jade lati ilẹ Egipti wá, nwọn si ntọ̀ ọlọrun miran lẹhin, ninu oriṣa awọn enia ti o yi wọn ká kiri, nwọn si nfi ori wọn balẹ fun wọn, nwọn si bi OLUWA ninu.

13 Nwọn si kọ̀ OLUWA silẹ, nwọn si nsìn Baali ati Aṣtarotu.

14 Ibinu OLUWA si rú si Israeli, o si fi wọn lé awọn akolohun lọwọ, ti o kó wọn lẹrù, o si tà wọn si ọwọ́ awọn ọtá wọn yiká kiri, tobẹ̃ ti nwọn kò le duro mọ́ niwaju awọn ọtá wọn.

15 Nibikibi ti nwọn ba jade lọ, ọwọ́ OLUWA wà lara wọn fun buburu, gẹgẹ bi OLUWA ti wi, ati gẹgẹ bi OLUWA ti bura fun wọn: oju si pọ́n wọn pupọ̀pupọ.

16 OLUWA si gbé awọn onidajọ dide, ti o gbà wọn li ọwọ́ awọn ẹniti nkó wọn lẹrù.

17 Sibẹ̀sibẹ nwọn kò fetisi ti awọn onidajọ wọn, nitoriti nwọn ṣe panṣaga tọ̀ ọlọrun miran lẹhin, nwọn si fi ori wọn balẹ fun wọn: nwọn yipada kánkan kuro li ọ̀na ti awọn baba wọn ti rìn, ni gbigbà ofin OLUWA gbọ́; awọn kò ṣe bẹ̃.

18 Nigbati OLUWA ba si gbé awọn onidajọ dide fun wọn, OLUWA a si wà pẹlu onidajọ na, on a si gbà wọn kuro li ọwọ́ awọn ọtá wọn ni gbogbo ọjọ́ onidajọ na: nitoriti OLUWA kãnu, nitori ikerora wọn nitori awọn ti npọ́n wọn loju, ti nwọn si nni wọn lara.

19 O si ṣe, nigbati onidajọ na ba kú, nwọn a si pada, nwọn a si bà ara wọn jẹ́ jù awọn baba wọn lọ, ni titọ̀ ọlọrun miran lẹhin lati ma sìn wọn, ati lati ma fi ori balẹ fun wọn; nwọn kò dẹkun iṣe wọn, ati ìwa-agidi wọn.

20 Ibinu OLUWA si rú si Israeli; o si wipe, Nitoriti orilẹ-ède yi ti re majẹmu mi kọja eyiti mo ti palaṣẹ fun awọn baba wọn, ti nwọn kò si gbọ́ ohùn mi;

21 Emi pẹlu ki yio lé ọkan jade mọ́ kuro niwaju wọn ninu awọn orilẹ-ède, ti Joṣua fisilẹ nigbati o kú:

22 Ki emi ki o le ma fi wọn dan Israeli wò, bi nwọn o ma ṣe akiyesi ọ̀na OLUWA lati ma rìn ninu rẹ̀, bi awọn baba wọn ti ṣe akiyesi rẹ̀, tabi bi nwọn ki yio ṣe e.

23 OLUWA si fi orilẹ-ède wọnni silẹ, li ailé wọn jade kánkan; bẹ̃ni kò si fi wọn lé Joṣua lọwọ.

## ORI 3.

NJẸ wọnyi li awọn orilẹ-ède ti OLUWA fisilẹ, lati ma fi wọn dan Israeli wò, ani iye awọn ti kò mọ̀ gbogbo ogun Kenaani;

2 Nitori idí yi pe, ki iran awọn ọmọ Israeli ki o le mọ̀, lati ma kọ́ wọn li ogun, ani irú awọn ti kò ti mọ̀ ọ nigbaju rí;

3 Awọn ijoye Filistini marun, ati gbogbo awọn Kenaani, ati awọn ara Sidoni, ati awọn Hifi ti ngbé òke Lebanoni, lati òke Baalihermoni lọ dé atiwọ̀ Hamati.

4 Wọnyi li a o si ma fi dan Israeli wò, lati mọ̀ bi nwọn o fetisi ofin OLUWA, ti o fi fun awọn baba wọn lati ọwọ́ Mose wá.

5 Awọn ọmọ Israeli si joko lãrin awọn ara Kenaani; ati awọn Hitti, ati awọn Amori, ati awọn Perissi, ati awọn Hifi, ati awọn Jebusi:

6 Nwọn si fẹ́ awọn ọmọbirin wọn li aya, nwọn si fi awọn ọmọbirin wọn fun awọn ọmọkọnrin wọn, nwọn si nsìn awọn oriṣa wọn.

7 Awọn ọmọ Israeli si ṣe eyiti o buru li oju OLUWA, nwọn si gbàgbé OLUWA Ọlọrun wọn, nwọn si nsìn Baalimu at Aṣerotu.

8 Nitori na ibinu OLUWA ru si Israeli, o si tà wọn si ọwọ́ Kuṣani-riṣataimu ọba Mesopotamia: awọn ọmọ Israeli si sìn Kuṣani-riṣataimu li ọdún mẹjọ.

9 Nigbati awọn ọmọ Israeli si kigbepè OLUWA, OLUWA si gbé olugbala kan dide fun awọn ọmọ Israeli, ẹniti o gbà wọn, ani Otnĩeli ọmọ Kenasi, aburò Kalebu.

10 Ẹmi OLUWA si wà lara rẹ̀, on si ṣe idajọ Israeli, o si jade ogun, OLUWA si fi Kuṣani-riṣataimu ọba Mesopotamia lé e lọwọ: ọwọ́ rẹ̀ si bori Kuṣani-riṣataimu.

11 Ilẹ na si simi li ogoji ọdún. Otnieli ọmọ Kenasi si kú.

12 Awọn ọmọ Israeli si tun ṣe eyiti o buru loju OLUWA: OLUWA si fi agbara fun Egloni ọba Moabu si Israeli, nitoripe nwọn ti ṣe eyiti o buru li oju OLUWA.

13 O si kó awọn ọmọ Ammoni ati ti Amaleki mọra rẹ̀; o si lọ o kọlù Israeli, nwọn si gbà ilu ọpẹ.

14 Awọn ọmọ Israeli si sìn Egloni ọba Moabu li ọdún mejidilogun.

Digitized by Google

15 Ṣugbọn nigbati awọn ọmọ Israeli
kigbepè OLUWA, OLUWA si gbé olugbala
kan dide fun wọn, Ehudu ọmọ Gera, ẹ̀ya
Benjamini, ọlọwọ́-òsi: awọn ọmọ Israeli si
fi ẹ̀bun rán a si Egloni ọba Moabu.
16 Ehudu si rọ idà kan olojumeji, igbọn-
wọ kan ni gigùn; on si sán a si abẹ aṣọ rẹ̀
ni itan ọtún.
17 O si mú ọrẹ na wá fun Egloni ọba
Moabu; Egloni si jẹ́ ọkọnrin ti o sanra
pipọ̀.
18 Nigbati o si fi ọrẹ na fun u tán, o rán
awọn enia ti o rù ọrẹ na pada lọ.
19 Ṣugbọn on tikara rẹ̀ pada lati ibi ere
finfin ti o wà leti Gilgali, o si wipe, Ọba,
mo lí ọ̀rọ ìkọkọ kan ibá ọ sọ. On si wipe,
Ẹ dakẹ. Gbogbo awọn ẹniti o duro tì i si
jade kuro lọdọ rẹ̀.
20 Ehudu si tọ̀ ọ wá; on si nikan joko
ninu yará itura rẹ̀. Ehudu si wipe, Mo lí
ọ̀rọ kan lati ọdọ Ọlọrun wá fun ọ. On si
dide kuro ni ibujoko rẹ̀.
21 Ehudu si nà ọwọ́ òsi rẹ̀, o si yọ idà
na kuro ni itan ọtún rẹ̀, o si fi gún u ni
ikùn:
22 Ati idà ati ekù si wọle; ọrá si bò idà
na nitoriti kò fà idà na yọ kuro ninu ikun
rẹ̀; o si yọ lẹhin.
23 Nigbana ni Ehudu si ba ti iloro lọ, o
si se ilẹkun gbangan na mọ́ ọ, o si tì wọn.
24 Nigbati o si jade lọ tán, awọn iranṣẹ
rẹ̀ dé; nigbati nwọn wò, si kiye si i, awọn
ilẹkun gbangan tì; nwọn wipe, Li aisí ani-
ani o bò ẹsẹ̀ rẹ̀ ninu yará itura rẹ̀.
25 Nwọn si duro titi o fi di itiju fun
wọn: kiyesi i on kò si ṣí ilẹkun gbangan
na silẹ; nitorina nwọn mú ọmọlẹkun, nwọn
si ṣí i: si kiyesi i, oluwa wọn ti ṣubu lulẹ
kú.
26 Ehudu si sálọ nigbati nwọn nduro, o
si kọja ibi ere finfin, o si sálọ si Seira.
27 O si ṣe, nigbati o dé, o fọn ipè ni ilẹ
òke Efraimu, awọn ọmọ Israeli si bá a
sọkalẹ lọ lati òke na wá, on si wà niwaju
wọn.
28 On si wi fun wọn pe, Ẹ ma tọ̀ mi
lẹhin: nitoriti OLUWA ti fi awọn ọtá nyin
awọn ara Moabu lé nyin lọwọ. Nwọn si
sọkalẹ tọ̀ ọ lẹhin lọ, nwọn si gbà ìwọdo
Jordani, ti o wà ni ìha Moabu, nwọn kò si
jẹ ki ẹnikan ki o kọja mọ́.
29 Nwọn si pa ìwọn ẹgba marun ọkọn-
rin ninu awọn ara Moabu ni ìgba na, gbo-
gbo awọn ti o sigbọnlẹ, ati gbogbo awọn
akọni ọkọnrin; kò sí ọkọnrin kanṣoṣo ti o
sálà.
30 Bẹ̃li a tẹ̀ ori Moabu ba ni ijọ́ na li
abẹ ọwọ́ Israeli. Ilẹ na si simi li ọgọrin
ọdún.
31 Lẹhin rẹ̀ ni Ṣamgari ọmọ Anati, ẹniti
o fi ọpá ti a fi ndà akọmalu pa ẹgbẹta ọkọn-
rin ninu awọn ara Filistini, on pẹlu si gbà
Israeli.

## ORI 4.

AWỌN ọmọ Israeli si tun ṣe eyiti o buru
li oju OLUWA, nigbati Ehudu kú tán.
2 OLUWA si tà wọn si ọwọ́ Jabini ọba
Kenaani, ẹniti o jọba ni Hasori; olori ogun
ẹniti iṣe Sisera, ẹniti ngbé Haroṣeti ti awọn
orilẹ-ède.
3 Awọn ọmọ Israeli si kigbepè OLUWA:
nitoriti o ní ẹdẹgbẹrun kẹkẹ́ irin; ogun
ọdún li o si fi pọ́n awọn ọmọ Israeli loju
gidigidi.
4 Ati Debora, wolí-obirin, aya Lappidotu,
o ṣe idajọ Israeli li akokò na.
5 On si ngbé abẹ igi-ọpẹ Debora li agbe-
demeji Rama ati Beti-eli ni ilẹ òke Efrai-
mu: awọn ọmọ Israeli a si ma wá sọdọ rẹ̀
fun idajọ.
6 On si ranṣẹ pè Baraki ọmọ Abinoamu
lati Kedeṣi-naftali jade wá, o si wi fun u
pe, OLUWA, Ọlọrun Israeli kò ha ti paṣẹ
pe, Lọ sùnmọ òke Tabori, ki o si mú ẹgba
marun ọkọnrin ninu awọn ọmọ Naftali, ati
ninu awọn ọmọ Sebuluni pẹlu rẹ.
7 Emi o si fà Sisera, olori ogun Jabini,
pẹlu kẹkẹ́ rẹ̀ ati ogun rẹ̀, sọdọ rẹ si odò
Kiṣoni; emi o si fi i lé ọ lọwọ.
8 Baraki si wi fun u pe, Bi iwọ o ba bá
mi lọ, njẹ emi o lọ: ṣugbọn bi iwọ ki yio
ba bá mi lọ, emi ki yio lọ.
9 On si wipe, Ni lilọ emi o bá ọ lọ:
ṣugbọn ọlá ọ̀na ti iwọ nlọ nì ki yio jẹ́ tirẹ;
nitoriti OLUWA yio tà Sisera si ọwọ́ obirin.
Debora si dide, o si bá Baraki lọ si Kedeṣi.
10 Baraki si pè Sebuluni ati Naftali si
Kedeṣi; on si lọ pẹlu ẹgba marun ọkọnrin
lẹhin rẹ̀: Debora si gòke lọ pẹlu rẹ̀.
11 Njẹ Heberi ọmọ Keni, ti yà ara rẹ̀
kuro lọdọ awọn ọmọ Keni, ani awọn ọmọ
Hobabu, ana Mose, o si pa agọ́ rẹ̀ titi dé
igi-oaku Saanannimu, ti o wà li àgbegbe
Kedeṣi.
12 Nwọn si sọ fun Sisera pe, Baraki ọmọ
Abinoamu ti lọ si òke Tabori.
13 Sisera si kó gbogbo kẹkẹ́ rẹ̀ jọ, ẹdẹ-
gbẹrun kẹkẹ́ irin, ati gbogbo awọn enia ti
o wà pẹlu rẹ̀, lati Haroṣeti awọn orilẹ-ède
wá si odò Kiṣoni.
14 Debora si wi fun Baraki pe, Dide;

Digitized by Google

nitoripe oni li ọjọ́ ti OLUWA fi Sisera lé ọ
lọwọ: OLUWA kò ha ti ṣaju rẹ lọ bi? Bẹ̃ni
Baraki sọkalẹ lati òke Tabori lọ, ẹgba marun
ọkọnrin si tẹle e lẹhin.
15 OLUWA si fi oju idà ṣẹgun Sisera, ati
gbogbo kẹkẹ́ rẹ̀, ati gbogbo ogun rẹ̀, niwaju
Baraki; Sisera si sọkalẹ kuro li ori kẹkẹ́
rẹ̀, o si fi ẹsẹ̀ rẹ̀ sálọ.
16 Ṣugbọn Baraki lepa awọn kẹkẹ́, ati
ogun na, titi dé Haroṣeti awọn orilẹ-ède:
gbogbo ogun Sisera si ti oju idà ṣubu;
ọkọnrin kanṣoṣo kò si kù.
17 Ṣugbọn Sisera ti fi ẹsẹ̀ rẹ̀ sálọ si agọ́
Jaeli aya Heberi ọmọ Keni: nitoriti alafia
wà lãrin Jabini ọba Hasori ati ile Heberi
ọmọ Keni.
18 Jaeli si jade lọ ipade Sisera, o si wi
fun u pe, Yà wá, oluwa mi, yà sọdọ mi;
má bẹ̀ru. On si yà sọdọ rẹ̀ sinu agọ́, o si
fi kubusu bò o.
19 On si wi fun u pe, Emi bẹ̀ ọ, fun mi
li omi diẹ mu; nitoriti ongbẹ ngbẹ mi. O
si ṣí igo warà kan, o si fi fun u mu, o si bò
o lara.
20 On si wi fun u pe, Duro li ẹnu-ọ̀na
agọ́, yio si ṣe, bi ẹnikan ba wá, ti o si bi ọ
lère pe, Ọkọnrin kan wà nihin bi? ki iwọ
wipe, Kò sí.
21 Nigbana ni Jaeli aya Heberi mú iṣo-
agọ́ kan, o si mú òlu li ọwọ́ rẹ̀, o si yọ́ tọ̀ ọ,
o si kàn iṣo na mọ́ ẹbati rẹ̀, o si wọ̀ ilẹ ṣin-
ṣin; nitoriti o sùn fọnfọn; bẹ̃ni o daku, o
si kú.
22 Si kiyesi i, bi Baraki ti nlepa Sisera,
Jaeli wá pade rẹ̀, o si wi fun u pe, Wá, emi
o si fi ọkọnrin ti iwọ nwá hàn ọ. O si wá
sọdọ rẹ̀; si kiyesi i, Sisera dubulẹ li okú,
iṣo-agọ́ na si wà li ẹbati rẹ̀.
23 Bẹ̃li Ọlọrun si tẹ̀ ori Jabini ọba
Kenaani ba li ọjọ́ na niwaju awọn ọmọ
Israeli.
24 Ọwọ́ awọn ọmọ Israeli si le siwaju ati
siwaju si Jabini ọba Kenaani, titi nwọn fi
run Jabini ọba Kenaani.

## ORI 5.

NIGBANA ni Debora on Baraki ọmọ
Abinoamu kọrin li ọjọ́ na, wipe,
2 Nitori bi awọn olori ti ṣaju ni Israeli,
nitori bi awọn enia ti fi tinutinu wá, ẹ fi
ibukún fun OLUWA.
3 Ẹ gbọ́, ẹnyin ọba; ẹ feti nyin silẹ,
ẹnyin ọmọ alade; emi, ani emi, o kọrin si
OLUWA; emi o kọrin iyìn si OLUWA Ọlọrun
Israeli.
4 OLUWA, nigbati iwọ jade kuro ni Seiri,
nigbati iwọ nyan jade lati pápa Edomu wá,
ilẹ mìtiti, awọn ọrun si kánsilẹ, ani awọ-
sanma pẹlu kán omi silẹ.
5 Awọn òkenla yọ́ niwaju OLUWA, ani
Sinai yi niwaju OLUWA, Ọlọrun Israeli.
6 Li ọjọ́ Ṣamgari ọmọ Anati, li ọjọ́ Jaeli,
awọn ọ̀na opópo da, awọn èro si nrìn li ọ̀na
ìkọkọ.
7 Awọn olori tán ni Israeli, nwọn tán,
titi emi Debora fi dide, ti emi dide bi iya
ni Israeli.
8 Nwọn ti yàn ọlọrun titun; nigbana li
ogun wà ni ibode: a ha ri asà tabi ọ̀kọ kan
lãrin ẹgba ogún ni Israeli bi?
9 Aiya mi fà si awọn alaṣẹ Israeli, awọn
ti nwọn fi tinutinu wá ninu awọn enia: ẹ
fi ibukún fun OLUWA.
10 Ẹ sọ ọ, ẹnyin ti ngùn kẹtẹkẹtẹ fun-
fun, ẹnyin ti njoko lori ẹni daradara, ati
ẹnyin ti nrìn li ọ̀na.
11 Li ọ̀na jijìn si ariwo awọn tafàtafa
nibiti a gbé nfà omi, nibẹ̀ ni nwọn o gbé sọ
iṣẹ ododo OLUWA, ani iṣẹ ododo ijọba rẹ̀ ni
Israeli. Nigbana ni awọn enia OLUWA sọ-
kalẹ lọ si ibode.
12 Jí, jí, Debora; Jí, jí, kọ orin: dide,
Baraki, ki o si ma kó awọn igbekun rẹ ni
igbekun, iwọ ọmọ Abinoamu.
13 Nigbana ni iyokù ninu awọn ọ̀lọtọ
ati awọn enia sọkalẹ; OLUWA sọkalẹ sori
awọn alagbara fun mi.
14 Lati Efraimu ni nwọn ti wá awọn ti
gbongbo wọn wà ni Amaleki; lẹhin rẹ,
Benjamini, lãrin awọn enia rẹ; lati Makiri
li awọn alaṣẹ ti sọkalẹ wa, ati lati Sebuluni
li awọn ẹniti nmú ọpá oyè lọwọ.
15 Awọn ọmọ-alade Issakari wà pẹlu
Debora; bi Issakari ti ri, bẹ̃ni Baraki;
nwọn sure li ẹsẹ̀ lọ si afonifoji na. Ni
ipadò Reubeni ni ìgbero pipọ̀ wà.
16 Eṣe ti iwọ fi joko lãrin agbo agutan
lati ma gbọ́ fere oluṣọ-agutan? Ni ipadò
Reubeni ni ìgbero pipọ̀ wà.
17 Gileadi joko loke odò Jordani: ẽṣe ti
Dani fi joko ninu ọkọ̀? Aṣeri joko leti
okun, o si ngbé ebute rẹ̀.
18 Sebuluni li awọn enia, ti o fi ẹmi wọn
wewu ikú, ati Naftali, ni ibi giga pápa.
19 Awọn ọba wá nwọn jà; nigbana li
awọn ọba Kenaani jà ni Taanaki leti odò
Megiddo: nwọn kò si gbà ère owo.
20 Nwọn jà lati ọrun wá, awọn irawọ ni
ipa wọn bá Sisera jà.
21 Odò Kiṣoni gbá wọn lọ, odò igbani,
odò Kiṣoni. Hã ọkàn mi, ma yan lọ ninu
agbara.

Digitized by Google

22 Nigbana ni patako ẹsẹ̀ ẹṣin kì ilẹ, nitori ire-sisá, iré-sisá awọn alagbara wọn.

23 Ẹ fi Merosi bú, bẹ̀li angeli OLUWA wi, ẹ fi awọn ara inu rẹ̀ bú ibú kikorò; nitoriti nwọn kò wá si iranlọwọ OLUWA, si iranlọwọ OLUWA si awọn alagbara.

24 Ibukún ni fun Jaeli aya Heberi ọmọ Keni jù awọn obirin lọ, ibukún ni fun u jù awọn obirin lọ ninu agọ́.

25 O bère omi, o fun u ni warà; o mu ori-amọ tọ̀ ọ wá ninu awo iyebiye.

26 O nà ọwọ́ rẹ̀ mú iṣo, ati ọwọ́ ọtún rẹ̀ mú òlu awọn ọlọnà; òlu na li o si fi lù Sisera, o gba mọ́ ọ li ori, o si gún o si kàn ẹbati rẹ̀ mọlẹ ṣinṣin.

27 Li ẹsẹ̀ rẹ̀ o wolẹ, o ṣubu, o dubulẹ: li ẹsẹ̀ rẹ̀ o wolẹ, o ṣubu: ni ibi ti o gbè wolẹ, nibẹ̀ na li o ṣubu kú.

28 Iya Sisera nwò oju-ferese, o si kigbe, o kigbe li oju-ferese ọlọnà pe; Ēṣe ti kẹkẹ́ rẹ̀ fi pẹ bẹ̃ lati dé? Ēṣe ti ẹsẹ̀ kẹkẹ̀ rẹ̀ fi duro lẹhin?

29 Awọn obirin rẹ̀ amoye da a lohùn, ani, on si ti da ara rẹ̀ lohùn pe,

30 Nwọn kò ha ti ri, nwọn kò ha ti pín ikogun bi? fun olukuluku ọkọnrin wundia kan tabi meji; fun Sisera ikogun-aṣọ alarabara, ikogun-aṣọ alarabara oniṣẹ-abẹ́rẹ, aṣọ alarabara oniṣẹ-abẹ́rẹ ni ìha mejeji, li ọrùn awọn ti a kó li ogun.

31 Bẹ̃ni ki o jẹ ki gbogbo awọn ọtá rẹ ki o ṣegbé OLUWA: ṣugbọn jẹ ki awọn ẹniti o fẹ́ ẹ ki o dabi õrùn nigbati o ba yọ ninu agbara rẹ̀. Ilẹ na si simi li ogoji ọdún.

## ORI 6.

AWỌN ọmọ Israeli si ṣe buburu loju OLUWA: OLUWA si fi wọn lé Midiani lọwọ li ọdún meje.

2 Ọwọ́ Midiani si le si Israeli: ati nitori Midiani awọn ọmọ Israeli wà ihò wọnni fun ara wọn, ti o wà ninu òke, ati ninu ọgbun, ati ni ibi-agbara wọnni.

3 O si ṣe, bi Israeli ba gbìn irugbìn, awọn Midiani a si gòke wá, ati awọn Amaleki, ati awọn ọmọ ìha ìla-õrùn; nwọn a si gòke tọ̀ wọn wá;

4 Nwọn a si dótì wọn, nwọn a si run eso ilẹ na, titi iwọ o fi dé Gasa, nwọn ki isi fi onjẹ silẹ ni Israeli, tabi agutan, tabi akọmalu, tabi kẹtẹkẹtẹ.

5 Nitoriti nwọn gòke wá ti awọn ti ohunọ̀sin wọn ati agọ́ wọn, nwọn si wá bi eṣú li ọ̀pọlọpọ; awọn ati awọn ibakasiẹ wọn jẹ́ ainiye: nwọn si wọ̀ inu ilẹ na lati jẹ ẹ run.

6 Oju si pọ́n Israeli gidigidi nitori awọn Midiani; awọn ọmọ Israeli si kigbepè OLUWA.

7 O si ṣe, nigbati awọn ọmọ Israeli kigbepè OLUWA nitori awọn Midiani,

8 OLUWA si rán wolĩ kan si awọn ọmọ Israeli: ẹniti o wi fun wọn pe, Bayi li OLUWA, Ọlọrun Israeli wi, Emi mú nyin gòke ti Egipti wá, mo si mú nyin jade kuro li oko-ẹrú;

9 Emi si gbà nyin li ọwọ́ awọn ara Egipti, ati li ọwọ́ gbogbo awọn ti npọ́n nyin loju, mo si lé wọn kuro niwaju nyin, mo si fi ilẹ wọn fun nyin;

10 Mo si wi fun nyin pe, Emi li OLUWA Ọlọrun nyin; ẹ máṣe bẹ̀ru oriṣa awọn Amori, ilẹ ẹniti ẹnyin ngbé: ṣugbọn ẹnyin kò gbà ohùn mi gbọ́.

11 Angeli OLUWA kan si wá, o si joko labẹ igi-oaku kan ti o wà ni Ofra, ti iṣe ti Joaṣi ọmọ Abiesri: Gideoni ọmọ rẹ̀ si npakà nibi ifọnti, lati fi i pamọ́ kuro loju awọn Midiani.

12 Angeli OLUWA na si farahàn a, o si wi fun u pe, OLUWA wà pẹlu rẹ, iwọ ọkọnrin alagbara.

13 Gideoni si wi fun u pe, Yẽ oluwa mi, ibaṣepe OLUWA wà pẹlu wa, njẹ ēṣe ti gbogbo eyi fi bá wa? nibo ni gbogbo iṣẹ-iyanu rẹ̀ ti awọn baba wa ti sọ fun wa gbe wà, wipe, OLUWA kò ha mú wa gòke lati Egipti wa? ṣugbọn nisisiyi OLUWA ti kọ̀ wa silẹ, o si ti fi wa lé Midiani lọwọ.

14 OLUWA si wò o, o si wipe, Lọ ninu agbara rẹ yi, ki iwọ ki si gbà Israeli là kuro lọwọ Midiani: Emi kọ ha rán ọ bi?

15 O si wi fun u pe, Yẽ oluwa mi, ọ̀na wo li emi o fi gbà Israeli là? kiyesi i, talakà ni idile mi ni Manasse, emi li o si jẹ́ ẹni ikẹhin ni ile baba mi.

16 OLUWA si wi fun u pe, Nitõtọ emi o wà pẹlu rẹ, iwọ o si kọlù awọn Midiani bi ọkọnrin kan.

17 On si wi fun u pe, Bi o ba ṣepe mo ri ore-ọfẹ gbà li oju rẹ, njẹ fi àmi kan hàn mi pe iwọ bá mi sọ̀rọ.

18 Máṣe lọ kuro nihin, emi bẹ̀ ọ, titi emi o fi tọ̀ ọ wá, ti emi o si fi mú ọrẹ mi fun ọ wá, ati ti emi o si fi gbé e kalẹ niwaju rẹ. On si wipe, Emi o duro titi iwọ o si fi padawá.

19 Gideoni si wọ̀ inu ile lọ, o si pèse ọmọ ewurẹ kan, ati akara alaiwu ti iyẹfun òṣuwọn efa kan: ẹran na li o fi sinu agbọ̀n, omi rẹ̀ li o si fi sinu ìkoko, o si gbé e jade

Digitized by Google

tọ̀ ọ wá labẹ igi-oaku na, o si gbé e siwaju
rẹ̀.
20 Angẹli Ọlọrun na si wi fun u pe, Mú
ẹran na, ati àkara alaiwu na, ki o si fi wọn
lé ori okuta yi, ki o si dà omi ẹran na silẹ.
On si ṣe bẹ̃.
21 Nigbana ni angẹli OLUWA nà ọpá ti
o wà li ọwọ rẹ̀, o si fi ori rẹ̀ kàn ẹran na ati
akara alaiwu na; iná si là lati inu okuta
na jade, o si jó ẹran na, ati àkara alaiwu;
angẹli OLUWA na si lọ kuro niwaju rẹ̀.
22 Gideoni si ri pe angẹli OLUWA ni;
Gideoni si wipe, Mo gbé, OLUWA Ọlọrun!
nitoriti emi ri angẹli OLUWA li ojukoju.
23 OLUWA si wi fun u pe, Alafia fun ọ;
má ṣe bẹ̀ru: iwọ ki yio kú.
24 Nigbana ni Gideoni mọ pẹpẹ kan nibẹ̀
fun OLUWA, o si pè orukọ rẹ̀ ni Jehofa-
ṣalomu: o wà ni Ofra ti awọn Abiesri sibẹ̀
titi di oni.
25 O si ṣe li oru ọjọ́ kanna, li OLUWA
wi fun u pe, Mú akọmalu baba rẹ, ani akọ-
malu keji ọlọdún meje, ki o si wó pẹpẹ
Baali ti baba rẹ ní lulẹ ki o si bẹ́ igi-oriṣa
ti o wà lẹba rẹ̀ lulẹ:
26 Ki o si mọ pẹpẹ kan fun OLUWA
Ọlọrun rẹ lori ibi agbara yi, bi o ti yẹ, ki o
si mú akọmalu keji, ki o si fi igi oriṣa ti iwọ
bẹ́ lulẹ ru ẹbọ sisun.
27 Nigbana ni Gideoni mú ọkọnrin
mẹwa ninu awọn iranṣẹ rẹ̀, o si ṣe bi OLU-
WA ti sọ fun u: o si ṣe, nitoripe o bẹ̀ru ile
baba rẹ̀ ati awọn ọkọnrin ilu na, tobẹ̃ ti kò
fi le ṣe e li ọsán, ti o si fi ṣe e li oru.
28 Nigbati awọn ọkọnrin ilu na si dide
ni kùtukutu, si wò o, a ti wó pẹpẹ Baali
lulẹ, a si bẹ́ igi-oriṣa lulẹ ti o wà lẹba rẹ̀, a
si ti pa akọmalu keji rubọ lori pẹpẹ ti a
mọ.
29 Nwọn si sọ fun ara wọn pe, Tali o ṣe
nkan yi? Nigbati nwọn tọ̀sẹ̀, ti nwọn si
bère, nwọn si wipe, Gideoni ọmọ Joaṣi li o
ṣe nkan yi.
30 Nigbana li awọn ọkọnrin ilu na wi
fun Joaṣi pe, Mú ọmọ rẹ jade wá ki o le
kú: nitoripe o wó pẹpẹ Baali lulẹ, ati ito-
riti o bẹ́ igi-oriṣa ti o wà lẹba rẹ̀ lulẹ.
31 Joaṣi si wi fun gbogbo awọn ti o duro
tì i pe, Ẹnyin o gbèja Baali bi? tabi ẹnyin
o gbà a là bi? ẹniti o ba ngbèja rẹ̀, ẹ jẹ ki
a lù oluwarẹ̀ pa ni kùtukutu owurọ yi: bi
on iba ṣe ọlọrun, ẹ jẹ ki o gbèja ara rẹ̀,
nitoriti ẹnikan wó pẹpẹ rẹ̀ lulẹ.
32 Nitorina li ọjọ́ na, o pè orukọ rẹ̀ ni
Jerubbaali, wipe, Jẹ ki Baali ki o bá a jà,
nitoriti o wó pẹpẹ rẹ̀ lulẹ.
33 Nigbana ni gbogbo awọn Midiani ati
awọn Amaleki, ati awọn ọmọ ìha ìla-õrùn
kó ara wọn jọ pọ̀; nwọn rekọja, nwọn si
dó li afonifoji Jesreeli.
34 Ṣugbọn ẹmi OLUWA bà lé Gideoni,
on si fun ipè; Abieseri si kójọ sẹhin rẹ̀.
35 On si rán onṣẹ si gbogbo Manasse;
awọn si kójọ sẹhin rẹ̀ pẹlu: o si rán onṣẹ
si Aṣeri, ati si Sebuluni, ati si Naftali;
nwọn si gòke wá lati pade wọn.
36 Gideoni si wi fun Ọlọrun pe, Bi iwọ
o ba ti ọwọ́ mi gbà Israeli là, bi iwọ ti wi,
37 Kiyesi i, emi o fi irun agutan le ilẹ-
pakà; bi o ba ṣepe ìri sẹ̀ sara kìki irun
nikan, ti gbogbo ilẹ si gbẹ, nigbana li emi
o mọ̀ pe iwọ o ti ọwọ́ mi gbà Israeli là,
gẹgẹ bi iwọ ti wi.
38 Bẹ̃li o si ri: nitoriti on dide ni kùtu-
kutu ijọ́ keji, o si fọ́n irun agutan na, o si
fọ́n ìri na kuro lara rẹ̀, ọpọ́n kan si kún fun
omi.
39 Gideoni si wi fun Ọlọrun pe, Má ṣe jẹ
ki ibinu rẹ ki o rú si mi, emi o sọ̀rọ lẹ̃kan-
ṣoṣo yi: emi bẹ̀ ọ, jẹ ki emi ki o fi irun na
ṣe idanwò lẹ̃kan yi; jẹ ki irun agutan ni-
kan ki o gbẹ, ṣugbọn ki ìri ki o wà lori
gbogbo ilẹ.
40 Ọlọrun si ṣe bẹ̃ li oru na: nitoriti
irun agutan na gbẹ, ìri si wà lori gbogbo
ilẹ na.

## ORI 7.

NIGBANA ni Jerubbaali, ti iṣe Gideoni,
ati gbogbo awọn enia ti o wà pẹlu rẹ̀,
dide ni kùtukutu, nwọn si dó lẹba orisun
Harodu: ibudo Midiani si wà ni ìha ariwa
wọn, nibi òke More, li afonifoji.
2 OLUWA si wi fun Gideoni pe, Awọn
enia ti o wà lọdọ rẹ pọ̀ju fun mi lati fi awọn
Midiani lé wọn lọwọ, ki Israeli ki o má ba
gbé ara wọn ga si mi, pe, Ọwọ́ mi li o gbà
mi là.
3 Njẹ nitorina, lọ kede li etí awọn enia
na, wipe, Ẹnikẹni ti o ba nfòya ti ẹ̀ru ba si
mbà, ki o pada lati òke Gileadi ki o si lọ.
Ẹgbã mọkanla si pada ninu awọn enia na;
awọn ti o kù si jẹ́ ẹgba marun.
4 OLUWA si wi fun Gideoni pe, Awọn
enia na pọ̀ju sibẹ̀; mú wọn sọkalẹ wá si
odò, nibẹ̀ li emi o gbé dan wọn wò fun ọ:
yio si ṣe, ẹniti mo ba wi fun ọ pe, Eyi ni
yio bá ọ lọ, on na ni yio bá ọ lọ; ẹnikẹni
ti mo ba si wi fun ẹ pe, Eyi ki yio bá ọ lọ,
on na ni ki yio si bá ọ lọ.
5 Bẹ̃li o mú awọn enia na wá si odò:
OLUWA si wi fun Gideoni pe, Olukuluku

Digitized by Google

ẹniti o ba fi ahọn rẹ̀ lá omi, bi ajá ti ma lá omi, on na ni ki iwọ ki o fi si apakan fun ara rẹ̀; bẹ̃ si li olukuluku ẹniti o kunlẹ li ẽkun rẹ̀ lati mu omi.

6 Iye awọn ẹniti o lá omi, ti nwọn fi ọwọ́ wọn si ẹnu wọn, jẹ́ ọdunrun ọkọnrin: ṣugbọn gbogbo awọn enia iyokù kunlẹ li ẽkun wọn lati mu omi.

7 OLUWA si wi fun Gideoni pe, Nipasẹ ọdunrun ọkọnrin wọnyi ti o lá omi li emi o gbà nyin, emi o si fi awọn Midiani lé ọ lọwọ: jẹ ki gbogbo awọn iyokù lọ olukuluku si ipò rẹ̀.

8 Awọn enia na si mu onjẹ ati ipè li ọwọ́ wọn: on si rán gbogbo Israeli lọ, olukuluku sinu agọ́ rẹ̀, o si da ọdunrin ọkọnrin ni duro: ibudó Midiani si wà nisalẹ rẹ̀ li afonifoji.

9 O si ṣe li oru na, ni OLUWA wi fun u pe, Dide, sọkalẹ lọ si ibudó; nitoriti mo ti fi i lé ọ lọwọ.

10 Ṣugbọn bi iwọ ba mbẹ̀ru lati sọkalẹ lọ, ki iwọ ati Pura iranṣẹ rẹ sọkalẹ lọ si ibudó:

11 Iwọ o si gbọ́ ohun ti nwọn nwi; lẹhin eyi ni ọwọ́ rẹ yio li agbara lati sọkalẹ lọ si ibudó. Nigbana ni ti on ti Pura iranṣẹ rẹ̀ sọkalẹ lọ si ìha opin awọn ti o hamora, ti o wà ni ibudó.

12 Awọn Midiani ati awọn Amaleki, ati gbogbo awọn ọmọ ìha ìla-õrùn tò lọ titi li afonifoji gẹgẹ bi eṣú li ọ̀pọlọpọ; ibakasiẹ wọn kò si ní iye, bi iyanrin ti mbẹ leti okun li ọ̀pọlọpọ.

13 Nigbati Gideoni si dé, kiyesi i, ọkọnrin kan nrọ́ alá fun ẹnikeji rẹ̀, o si wipe, Kiyesi i, emi lá alá kan, si wò o, àkara ọkàbarle kan ṣubu si ibudó Midiani, o si bọ́ sinu agọ́ kan, o si kọlù u tobẹ̃ ti o fi ṣubu, o si doju rẹ̀ de, agọ́ na si ṣubu.

14 Ekeji rẹ̀ si da a lohùn, wipe, Eyiyi ki iṣe ohun miran bikoṣe idà Gideoni ọmọ Joaṣi ọkọnrin kan ni Israeli: nitoripe Ọlọrun ti fi Midiani ati gbogbo ibudó lé e lọwọ.

15 O si ṣe, nigbati Gideoni gbọ́ rirọ alá na, ati itumọ̀ rẹ̀, o tẹriba; o si pada si ibudó Israeli, o si wipe, Ẹ dide; nitoriti OLUWA ti fi ogun Midiani lé nyin lọwọ.

16 On si pín ọdunrun ọkọnrin na si ẹgbẹ mẹta, o si fi ipè lé olukuluku wọn lọwọ, pẹlu ìṣa ofo, òtufu si wà ninu awọn ìṣa na.

17 On si wi fun wọn pe, Ẹ wò mi, ki ẹnyin ki o si ṣe bẹ̃ gẹgẹ: si kiyesi i, nigbati mo ba dé opin ibudó na, yio si ṣe, bi emi ba ti ṣe, bẹ̃ni ki ẹnyin ki o ṣe.

18 Nigbati mo ba fun ìpe, emi ati gbogbo awọn ti mbẹ lọdọ mi, nigbana ni ki ẹnyin pẹlu ki o fun ìpe yiká gbogbo ibudó na, ki ẹnyin ki o si wi pe, Fun OLUWA, ati fun Gideoni.

19 Bẹ̃ni Gideoni, ati ọgọrun ọkọnrin ti mbẹ lọdọ rẹ̀, wá si opin ibudó, ni ibẹ̀rẹ iṣọ́ ãrin, nigbati nwọn ṣẹṣẹ yàn iṣọ́ sode: nwọn fun ipè, nwọn si fọ́ ìṣa ti o wà li ọwọ́ wọn.

20 Ẹgbẹ mẹtẹta na si fun ipè wọn, nwọn si fọ́ ìṣa wọn, nwọn si mú awọn òtufu li ọwọ́ òsi wọn, ati ipè li ọwọ́ ọtún lati fun: nwọn si kigbe li ohùn rara pe, Idà OLUWA, ati ti Gideoni.

21 Olukuluku ọkọnrin si duro ni ipò rẹ̀ yi ibudó na ká: gbogbo ogun na si sure, nwọn si kigbe, nwọn si sá.

22 Awọn ọkọnrin na fun ọdunrun ipè, OLUWA si yí idà olukuluku si ẹnikeji rẹ̀, ati si gbogbo ogun na: ogun na si sá titi dé Beti-ṣita ni ìha Serera, dé àgbegbe Abeli-mehola, leti Tabati.

23 Awọn ọkọnrin Israeli si kó ara wọn jọ lati Naftali, ati lati Aṣeri, ati lati gbogbo Manasse wá, nwọn si lepa awọn Midiani.

24 Gideoni si rán onṣẹ lọ si gbogbo òke Efraimu, wipe, Ẹ sọkalẹ wá pade awọn Midiani, ki ẹ si tète gbà omi wọnni dé Beti-bara ani Jordani. Nigbana ni gbogbo awọn ọkọnrin Efraimu kó ara wọn jọ, nwọn si gbà omi wọnni, titi dé Beti-bara ani Jordani.

25 Nwọn si mú meji ninu awọn ọmọalade Midiani, Orebu ati Seebu; Orebu ni nwọn si pa lori apata Orebu, ati Seebu ni nwọn si pa ni ibi-ifọnti Seebu, nwọn si lepa awọn ara Midiani, nwọn si mú ori Orebu ati Seebu wá fi fun Gideoni li apa keji odò Jordani.

## ORI 8.

AWỌN ọkọnrin Efraimu si wi fun u pe, Kili eyiti iwọ ṣe si wa bayi, ti iwọ kò fi pè wa, nigbati iwọ nlọ bá awọn ara Midiani jà? Nwọn si bá a sọ̀ gidigidi.

2 On si wi fun wọn pe, Kini mo ha ṣe nisisiyi ti a le fiwe ti nyin? Ẽṣẹ́ àjara Efraimu kò ha san jù ikore-àjara Abieseri lọ?

3 Ọlọrun sá ti fi awọn ọmọ-alade Midiani lé nyin lọwọ, Orebu ati Seebu: kini mo si le ṣe bi nyin? Nigbana ni inu wọn tutù si i, nigbati o ti wi eyinì.

Digitized by Google

4 Gideoni si dé odò Jordani, o si rekọja, on ati ọdunrun ọkọnrin ti o wà lọdọ rẹ̀, o di ãrẹ, ṣugbọn nwọn nlepa sibẹ̀.

5 On si wi fun awọn ọkọnrin Sukkotu pe, Emi bẹ̀ nyin, ẹ fi ìṣu-àkara melokan fun awọn enia wọnyi ti ntọ̀ mi lẹhin; nitoriti o di ãrẹ fun wọn, emi si nlepa Seba ati Salmunna, awọn ọba Midiani.

6 Awọn ọmọ-alade Sukkotu si wi pe, ọwọ́ rẹ ha ti itẹ̀ Seba on Salmunna na, ti awa o fi fun awọn ogun rẹ li onjẹ?

7 Gideoni si wipe, Nitorina nigbati OLUWA ba fi Seba ati Salmunna lé mi lọwọ, nigbana li emi o fi ẹgún ijù, ati oṣuṣu yà ẹran ara nyin.

8 On si gòke lati ibẹ̀ lọ si Penueli, o si sọ fun wọn bẹ̃ gẹgẹ: awọn ọkọnrin Penueli si da a lohùn gẹgẹ bi awọn ara Sukkotu si ti da a lohùn.

9 On si wi fun awọn ọkọnrin Penueli pẹlu pe, Nigbati mo ba pada dé li alafia, emi o wó ile-ẹṣọ́ yi lulẹ̀.

10 Njẹ Seba at Salmunna wà ni Karkori, ogun wọn si wà pẹlu wọn, o to ìwọn ẹdẹgbajọ ọkọnrin, iye awọn ti o kù ninu gbogbo ogun awọn ọmọ ìha ìla-õrùn: nitoripe ẹgbã ọgọta ọkọnrin ti o yọ idà ti ṣubu.

11 Gideoni si gbà ọ̀na awọn ti ngbé inu agọ́ ni ìha-õrùn Noba ati Jogbeha gòke lọ, o si kọlù ogun na; nitoriti ogun na ti sọranù.

12 Seba ati Salmunna si sá; on si lepa wọn; o si mu awọn ọba Midiani mejeji na, Seba ati Salmunna, o si damu gbogbo ogun na.

13 Gideoni ọmọ Joaṣi si pada lẹhin ogun na, ni ibi ati gòke Heresi.

14 O si mú ọmọkọnrin kan ninu awọn ọkọnrin Sukkotu, o si bère lọwọ rẹ̀: on si ṣe apẹrẹ awọn ọmọ-alade Sukkotu fun u, ati awọn àgba ti o wà nibẹ̀, mẹtadilọgọrin ọkọnrin.

15 On si tọ̀ awọn ọkọnrin Sukkotu na wá, o si wi fun wọn pe, Wò Seba ati Salmunna, nitori awọn ẹniti ẹnyin fi gàn mi pe, Ọwọ́ rẹ ha ti tẹ Seba ati Salmunna na, ti awa o fi fun awọn ọkọnrin rẹ ti ãrẹ mu li onjẹ?

16 On si mú awọn àgbagba ilu na, ati ẹgún ijù ati oṣuṣu, o si fi kọ́ awọn ọkọnrin Sukkotu li ọgbọ́n.

17 On si wó ile-ẹṣọ́ Penueli, o si pa awọn ọkọnrin ilu na.

18 Nigbana li o sọ fun Seba ati Salmunna, wipe, Irú ọkọnrin wo li awọn ẹniti ẹnyin pa ni Taboru? Nwọn si dahùn, Bi iwọ ti ri, bẹ̃ni nwọn ri; olukuluku nwọn dabi awọn ọmọ ọba.

19 On si wipe, Arakọnrin mi ni nwọn, ọmọ iya mi ni nwọn iṣe: bi OLUWA ti wà, ibaṣepe ẹnyin da wọn si, emi kì ba pa nyin.

20 On si wi fun Jeteri arẹmọ rẹ̀ pe, Dide, ki o si pa wọn. Ṣugbọn ọmọkọnrin na kò fà idà rẹ̀ yọ: nitori ẹ̀ru bà a, nitoripe ọmọde ni iṣe.

21 Nigbana ni Seba ati Salmunna wipe, Iwọ dide, ki o si kọlù wa: nitoripe bi ọkọnrin ti ri, bẹ̃li agbara rẹ̀ ri. Gideoni si dide, o si pa Seba ati Salmunna, o si bọ́ ohun ọṣọ́ wọnni kuro li ọrùn ibakasiẹ wọn.

22 Nigbana li awọn ọkọnrin Israeli wi fun Gideoni pe, Iwọ ma ṣe olori wa, iwọ, ati ọmọ rẹ, ati ọmọ ọmọ rẹ pẹlu: nitoripe o gbà wa lọwọ awọn ara Midiani.

23 Gideoni si wi fun wọn pe, Emi ki yio ṣe olori nyin, bẹ̃ni ọmọ mi ki yio ṣe olori nyin: OLUWA ni yio ma ṣe alaṣẹ nyin.

24 Gideoni si wi fun wọn pe, Emi o bère nkan lọwọ nyin, pe ki olukuluku nyin ki o le fi oruka-etí ti mbẹ ninu ikogun rẹ̀ fun mi. (Nitoriti nwọn ní oruka-etí ti wurà, nitoripe ọmọ Iṣmaeli ni nwọn iṣe.)

25 Nwọn si dahùn wipe, Tinutinu li awa o fi mú wọn wá. Nwọn si tẹ́ aṣọ kan, olukuluku nwọn si sọ oruka-etí ikogun rẹ̀ si i.

26 Ìwọn oruka-etí wurà na ti o bère lọwọ wọn jẹ́ ẹdẹgbẹsan ṣekeli wurà: làika ohun ọṣọ́ wọnni, ati ohun sisorọ̀, ati aṣọ elesè-àluko ti o wà lara awọn ọba Midiani, ati li àika ẹ̀wọn ti o wà li ọrùn ibakasiẹ wọn.

27 Gideoni si fi i ṣe ẹ̀wu-efodu kan, o si fi i si ilu rẹ̀, ni Ofra: gbogbo Israeli si ṣe àgbere tọ̀ ọ lẹhin nibẹ̀: o si wa di idẹkun fun Gideoni, ati fun ile rẹ̀.

28 Bẹ̃li a si tẹ̀ ori Midiani ba niwaju awọn ọmọ Israeli, nwọn kò si gbé ori wọn soke mọ́. Ilẹ na si simi ni ogoji ọdún li ọjọ́ Gideoni.

29 Jerubbaali ọmọ Joaṣi si lọ o si ngbe ile rẹ̀.

30 Gideoni si ní ãdọrin ọmọkọnrin ti o bi fun ara rẹ̀: nitoripe o lí obirin pupọ̀.

31 Àle rẹ̀ ti o wà ni Ṣekemu, on pẹlu bi ọmọkọnrin kan fun u, orukọ ẹniti a npè ni Abimeleki.

32 Gideoni ọmọ Joaṣi si kú li ogbó ọjọ́, a si sin i si ibojì Joaṣi baba rẹ̀, ni Ofra ti awọn Abiesri.

33 O si ṣe, lojukanna ti Gideoni kú, li awọn ọmọ Israeli pada, nwọn si ṣe panṣaga

Digitized by Google

tọ̀ Baalimu lọ, nwọn si fi Baali-beriti ṣe
oriṣa wọn.
34 Awọn ọmọ Israeli kò si ranti OLUWA
Ọlọrun wọn, ẹniti o gbà wọn lọwọ gbogbo
awọn ọtá wọn ni ìha gbogbo:
35 Bẽni nwọn kò si ṣe ore fun ile Jerub-
baali, ti iṣe Gideoni, gẹgẹ bi gbogbo ire ti
o ti ṣe fun Israeli.

## ORI 9.

ABIMELEKI ọmọ Jerubbaali si lọ si Ṣe-
kemu sọdọ awọn arakọnrin iya rẹ̀, o si
bá wọn sọ̀rọ, ati gbogbo idile ile baba iya
rẹ̀, wipe,
2 Emi bẹ̀ nyin, ẹ sọ li etí gbogbo awọn
ọkọnrin Ṣekemu pe, Ewo li o rọ̀run fun
nyin, ki gbogbo awọn ọmọ Jerubbaali,
ãdọrin enia, ki o ṣe olori nyin, tabi ki
ẹnikan ki o ṣe olori nyin? ki ẹnyin ki o
ranti pẹlu pe, emi li egungun nyin, ati
ẹran ara nyin.
3 Awọn arakọnrin iya rẹ̀ si sọ gbogbo
ọ̀rọ wọnyi nitori rẹ̀ li etí gbogbo awọn
ọkọnrin Ṣekemu: àiya wọn si tẹ̀ si ti Abi-
meleki; nitori nwọn wipe, Arakọnrin wa
ni iṣe.
4 Nwọn si fun u li ãdọrin owo fadakà
lati inu ile Baali-beriti wá, Abimeleki si fi
i bẹ̀ awọn enia lasan ati alainilari li ọ̀wẹ,
nwọn si ntẹ̀le e.
5 On si lọ si ile baba rẹ̀ ni Ofra, o si pa
awọn arakọnrin rẹ̀ awọn ọmọ Jerubbaali,
ãdọrin enia, lori okuta kan: ṣugbọn o kù
Jotamu abikẹhin ọmọ Jerubbaali; nitoriti
o sapamọ́.
6 Gbogbo awọn ọkọnrin Ṣekemu si kó
ara wọn jọ, ati gbogbo awọn ara ile Millo,
nwọn lọ nwọn si fi Abimeleki jẹ́ ọba, ni ibi
igi-oaku ile-ẹṣọ́ ti mbẹ ni Ṣekemu.
7 Nigbati nwọn si sọ fun Jotamu, on si
lọ o si duro lori òke Gerisimu, o si gbé
ohùn rẹ̀ soke, o kigbe, o si wi fun wọn pe,
Ẹ fetisi ti emi, ẹnyin ọkọnrin Ṣekemu, ki
Ọlọrùn ki o le fetisi ti nyin.
8 Awọn igi lọ li akokò kan ki nwọn ki o
le fi ọba jẹ́ lori wọn; nwọn si wi fun igi
olifi pe, Wá jọba lori wa.
9 Ṣugbọn igi olifi wi fun wọn pe, Emi ha
le fi ọrá mi silẹ, nipa eyiti nwọn nfi mi
bù ọlá fun Ọlọrun ati enia, ki emi ki o si
wá ṣe olori igi?
10 Awọn igi si wi fun igi ọpọtọ́ pe, Iwọ
wá jọba lori wa.
11 Ṣugbọn igi ọpọtọ́ wi fun wọn pe, Emi
le fi adùn mi silẹ, ati eso mi daradara, ki
emi ki o si wá ṣe olori awọn igi?
12 Awọn igi si wi fun àjara pe, Iwọ wá
jọba lori wa.
13 Ajara si wi fun wọn pe, Ki emi ki o
fi ọti-waini mi silẹ, eyiti nmu inu Ọlọrun
ati enia dùn, ki emi ki o si wá ṣe olori
awọn igi?
14 Nigbana ni gbogbo igi si wi fun igi-
ẹgún pe, Iwọ wá jọba lori wa.
15 Igi-ẹgún si wi fun awọn igi pe, Bi o
ba ṣepe nitõtọ li ẹnyin fi emi jẹ́ ọba lori
nyin, njẹ ẹ wá sá si abẹ ojiji mi: bi kò ba
si ṣe bẹ̃, jẹ ki iná ki o ti inu igi-ẹgún jade
wá, ki o si jó awọn igi-kedari ti Lebanoni
run.
16 Njẹ nitorina, bi ẹnyin ba ṣe otitọ, ati
eyiti o pé, niti ẹnyin fi Abimeleki jẹ́ oba,
ati bi ẹnyin ba si ṣe rere si Jerubbaali ati
si ile rẹ̀, ti ẹnyin si ṣe si i gẹgẹ bi iṣe ọwọ́
rẹ̀;
17 (Nitoriti baba mi jà fun nyin, o si fi
ẹmi rẹ̀ wewu, o si gbà nyin kuro li ọwọ
Midiani:
18 Ẹnyin si dide si ile baba mi li oni,
ẹnyin si pa awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, ãdọrin
enia, lori okuta kan, ẹnyin si fi Abimeleki,
ọmọ iranṣẹbirin rẹ̀ jẹ́ ọba lori awọn Ṣeke-
mu, nitoriti arakọnrin nyin ni iṣe;)
19 Njẹ bi ẹnyin ba ṣe otitọ, ati eyiti o
pé si Jerubbaali ati si ile rẹ̀ li oni yi, njẹ ki
ẹnyin ki o ma yọ̀ si Abimeleki, ki on pẹlu
si ma yọ̀ si nyin:
20 Ṣugbọn bi kò ba si ri bẹ̃, jẹ ki iná ki
o ti ọdọ Abimeleki jade wá, ki o si jò awọn
ọkọnrin Ṣekemu run, ati ile Millò: jẹ ki
iná ki o si ti ọdọ awọn ọkọnrin Ṣekemu ati
ile Millò, jade wá, ki o si jó Abimeleki
run.
21 Jotamu si sí, o sálọ, o si lọ si Beeri,
o si joko sibẹ̀, nitori ìbẹru Abimeleki ara-
kọnrin rẹ̀.
22 Abimeleki si ṣe olori awọn ọmọ Isra-
eli li ọdún mẹta.
23 Ọlọrun si rán ẹmi buburu sãrin Abi-
meleki ati awọn ọkọnrin Ṣekemu; awọn
ọkọnrin Ṣekemu si fi arekereke bá Abime-
leki lò:
24 Ki ìwa-ìka ti a ti hù si awọn ãdọrin
ọmọ Jerubbaali ki o le wá, ati ẹ̀jẹ wọn sori
Abimeleki arakọnrin wọn, ẹniti o pa wọn;
ati sori awọn ọkọnrin Ṣekemu, awọn ẹniti
o ràn a lọwọ lati pa awọn arakọnrin rẹ̀.
25 Awọn ọkọnrin Ṣekemu si yàn awọn
enia ti o ba dè e lori òke, gbogbo awọn ti
nkọja lọdọ wọn ni nwọn si njà a li ole:
nwọn si sọ fun Abimeleki.
26 Gaali ọmọ Ebedi si wá ti on ti awọn

Digitized by Google

arakọnrin rẹ̀, nwọn si kọja lọ si Ṣekemu: awọn ọkọnrin Ṣekemu si gbẹkẹ wọn le e.

27 Nwọn si jade lọ si oko, nwọn si ká eso-àjara wọn, nwọn si fọn eso na, nwọn si nṣe ariya, nwọn si lọ si ile oriṣa wọn, nwọn si jẹ, nwọn si mu, nwọn si fi Abimeleki ré.

28 Gaali ọmọ Ebedi si wipe, Tani Abimeleki? ta si ni Ṣekemu, ti awa o fi ma sìn i? Ṣe ọmọ Jerubbaali ni iṣe? ati Sebulu ijoye rẹ̀? ẹ mã sìn awọn ọkọnrin Hamoru baba Ṣekemu: ṣugbon nitori kili awa o ha ṣe ma sìn on?

29 Awọn enia wọnyi iba wà ni ikawọ mi! nigbana ni emi iba ṣí Abimeleki ni ipò. On si wi fun Abimeleki pe, Gbá ogun kún ogun rẹ, ki o si jade.

30 Nigbati Sebulu alaṣẹ ilu na si gbọ́ ọ̀rọ Gaali ọmọ Ebedi, o binu gidigidi.

31 On si rán awọn onṣẹ ìkọkọ si Abimeleki, wipe, Kiyesi i, Gaali ọmọ Ebedi ati awọn arakọnrin rẹ̀ wá si Ṣekemu; si kiyesi i, nwọn rọ̀ ilu na si ọ.

32 Njẹ nitorina, dide li oru, iwọ ati awọn enia ti o wà pẹlu rẹ, ki ẹnyin ki o si ba sinu oko:

33 Yio si ṣe, li owurọ̀, lojukanna bi õrùn ba si ti là, ki iwọ ki o dide ni kùtukutu owurọ̀, ki iwọ ki o si kọlù ilu na: si kiyesi i, nigbati on ati awọn enia ti mbẹ lọdọ rẹ̀ ba jade tọ̀ ọ, nigbana ni ki iwọ ki o ṣe si wọn bi iwọ ba ti ri pe o yẹ.

34 Abimeleki si dide, ati gbogbo awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀ li oru, nwọn si ba ni ipa mẹrin leti Ṣekemu.

35 Gaali ọmọ Ebedi si jade, o si duro li ẹnu-ọ̀na ibode ilu na: Abimeleki si dide, ati awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀, kuro ni ibuba.

36 Nigbati Gaali si ri awọn enia na, o wi fun Sebulu pe, Wò o, awọn enia nti ori òke sọkalẹ wa. Sebulu si wi fun u pe, Ojiji òke wọnni ni iwọ ri bi ẹnipe enia.

37 Gaali si tun wipe, Wò o, awọn enia nti òke sọkalẹ li agbedemeji ilẹ wá, ẹgbẹ kan si nti ọ̀na igi-oaku Meonenimu wá.

38 Nigbana ni Sebulu wi fun u pe, Nibo li ẹnu rẹ wà nisisiyi, ti iwọ fi wipe, Tani Abimeleki, ti awa o fi ma sìn i? awọn enia ti iwọ ti gàn ki awọn wọnyi? jọwọ jade lọ, nisisiyi, ki o si bà wọn jà.

39 Gaali si jade niwaju awọn ọkọnrin Ṣekemu, o si bá Abimeleki jà.

40 Abimeleki si lé e, on si sá niwaju rẹ̀, ọ̀pọlọpọ ninu nwọn ti o gbọgbẹ si ṣubu, titi dé ẹnu-ọ̀na ibode.

41 Abimeleki si joko ni Aruma: Sebulu si tì Gaali ati awọn arakọnrin rẹ̀ jade, ki nwọn ki o má ṣe joko ni Ṣekemu.

42 O si ṣe ni ijọ keji, ti awọn enia si jade lọ sinu oko; nwọn si sọ fun Abimeleki.

43 On si mu awọn enia, o si pín wọn si ipa mẹta, o si ba ninu oko; o si wò, si kiyesi i, awọn enia nti ilu jade wá; on si dide si wọn, o si kọlù wọn.

44 Abimeleki, ati ẹgbẹ ti o wà lọdọ rẹ̀ sure siwaju, nwọn si duro li ẹnu-ọ̀na ibode ilu na: ẹgbẹ meji si sure si gbogbo awọn enia na ti o wà ninu oko, nwọn si kọlù wọn.

45 Abimeleki si bá ilu na jà ni gbogbo ọjọ́ na; on si kó ilu na, o si pa awọn enia ti o wà ninu rẹ̀, o si wó ilu na palẹ, o si fọn iyọ̀ si i.

46 Nigbati gbogbo awọn ọkọnrin ile-ẹṣọ́ Ṣekemu gbọ́, nwọn si wọ̀ inu ile-ẹṣọ́ oriṣa Eliberiti lọ.

47 A si sọ fun Abimeleki pe, gbogbo awọn ọkọnrin ile-ẹṣọ́ Ṣekemu kó ara wọn jọ pọ̀.

48 Abimeleki si gùn ori òke Salmoni lọ, on ati gbogbo enia ti o wà pẹlu rẹ̀; Abimeleki si mu ãke kan li ọwọ́ rẹ̀, o si ke ẹka kan kuro lara igi, o si mú u, o si gbé e lé ejika rẹ̀, o si wi fun awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀ pe, Ohun ti ẹnyin ri ti emi ṣe, ẹ yára, ki ẹ si ṣe bi emi ti ṣe.

49 Gbogbo awọn enia na pẹlu, olukuluku si ke ẹka tirẹ̀, nwọn si ntọ̀ Abimeleki lẹhin, nwọn si fi wọn sinu ile-ẹṣọ́ na, nwọn si tinabọ ile na mọ́ wọn; tobẹ̃ ti gbogbo awọn ọkọnrin ile-ẹṣọ́ Ṣekemu fi kú pẹlu, ìwọn ẹgbẹrun enia, ọkọnrin ati obirin.

50 Nigbana ni Abimeleki lọ si Tebesi, o si dótì Tebesi, o si kó o.

51 Ṣugbọn ile-ẹṣọ́ ti o lagbara wà ninu ilu na, nibẹ̀ ni gbogbo awọn ọkọnrin ati awọn obirin, ati gbogbo awọn ẹniti o wà ni ilu na gbé sá si, nwọn si fara wọn mọ́ ibẹ̀; nwọn si gòke ile-ẹṣọ́ na lọ.

52 Abimeleki si wá si ibi ile-ẹṣọ́ na, o si bá a jà, o si kusa si ẹnu-ọ̀na ile-ẹṣọ́ na lati fi iná si i.

53 Obirin kan si sọ ọlọ lù Abimeleki li ori, o si fọ́ ọ li agbári.

54 Nigbana li o pè ọmọkọnrin ti nrù ihamọra rẹ̀ kánkan, o si wi fun u pe, Fà idà rẹ yọ, ki o si pa mi, ki awọn enia ki o má ba wi nipa ti emi pe, Obirin li o pa a. Ọmọkọnrin rẹ̀ si gún u, bẹ̃li o si kú.

55 Nigbati awọn ọkọnrin Israeli si ri pe, Abimeleki kú, nwọn si lọ olukuluku si ipò rẹ̀.

Digitized by Google

56 Bayi li Ọlọrun san ìwabuburu Abi-
meleki, ti o ti hù si baba rẹ̀, niti pe, o pa
ãdọrin awọn arakọnrin rẹ̀:
57 Ati gbogbo ìwabuburu awọn ọkọnrin
Ṣekemu li Ọlọrun si múpada sori wọn:
egún Jotamu ọmọ Jerubbaali si ṣẹ sori wọn.

## ORI 10.

LẸHIN Abimeleki li ẹnikan si dide lati
gbà Israeli là, Tola ọmọ Pua, ọmọ
Dodo, ọkọnrin Issakari kan; o si ngbé
Ṣamiri li òke Efraimu.
2 On si ṣe idajọ Israeli li ọdún mẹta-
lelogun o si kú, a si sin i ni Ṣamiri.
3 Lẹhin rẹ̀ ni Jairi dide, ara Gileadi; o
si ṣe idajọ Israeli li ọdún mejilelogun.
4 On si ní ọgbọ̀n ọmọkọnrin ti ngùn
ọgbọ̀n ọmọ kẹtẹkẹtẹ, nwọn si ní ọgbọ̀n ilu
ti a npè ni Haffoti-jairi titi o fi di oni,
eyiti o wà ni ilẹ Gileadi.
5 Jairi si kú, a si sin i ni Kamoni.
6 Awọn ọmọ Israeli si tun ṣe eyiti iṣe
buburu li oju OLUWA, nwọn si nsìn Baali-
mu, ati Aṣtarotu, ati awọn oriṣa Siria, ati
awọn oriṣa Sidoni, ati awọn oriṣa Moabu,
ati awọn oriṣa awọn ọmọ Ammoni, ati
awọn oriṣa awọn Filistini; nwọn si kọ̀
OLUWA silẹ, nwọn kò si sìn i.
7 Ibinu OLUWA si rú si Israeli, o si tà
wọn si ọwọ́ awọn Filistini, ati si ọwọ́ awọn
ọmọ Ammoni.
8 Li ọdún na nwọn ni awọn ọmọ Israeli
lara, nwọn si pọ́n wọn loju: ọdún me-
jidilogun ni nwọn fi ni gbogbo awọn ọmọ
Israeli ti o wà ni ìha keji Jordani ni ilẹ
awọn Amori, ti o wà ni Gileadi, lara.
9 Awọn ọmọ Ammoni si gòke odò Jor-
dani lati bá Juda jà pẹlu, ati Benjamini,
ati ile Efraimu; a si ni Israeli lara gidigidi.
10 Awọn ọmọ Israeli si kepè OLUWA
wipe, Awa ti ṣẹ̀ si ọ, nitoriti awa ti kọ̀
Ọlọrun wa silẹ, a si nsìn Baalimu.
11 OLUWA si wi fun awọn ọmọ Israeli
pe, Emi kò ti gbà nyin kuro lọwọ awọn
ara Egipti, ati lọwọ awọn ọmọ Amori, ati
lọwọ awọn ọmọ Ammoni, ati lọwọ awọn
Filistini?
12 Awọn ara Sidoni pẹlu, ati awọn
Amaleki, ati awọn Maoni si ti npọ́n nyin
loju; ẹnyin kepè mi, emi si gbà nyin lọwọ
wọn.
13 Ṣugbọn ẹnyin kọ̀ mi silẹ, ẹ si nsìn
ọlọrun miran: nitorina emi ki yio tun gbà
nyin mọ́.
14 Ẹ lọ kigbepè awọn oriṣa ti ẹnyin ti
yàn; jẹ ki nwọn ki o gbà nyin li akokò
wahalà nyin.
15 Awọn ọmọ Israeli si wi fun OLUWA
pe, Awa ti ṣẹ̀: ohunkohun ti o ba tọ́ li oju
rẹ ni ki o fi wa ṣe; sá gbà wa li oni yi, awa
bẹ̀ ọ.
16 Nwọn si kó ajeji ọlọrun wọnni ti o
wà lọdọ wọn kuro, nwọn si nsìn OLUWA:
ọkàn rẹ̀ kò si gbà òṣi Israeli mọ́.
17 Nigbana ni awọn ọmọ Ammoni kó
ara wọn jọ nwọn si dó si Gileadi. Awọn
ọmọ Israeli si kó ara wọn jọ, nwọn si dó si
Mispa.
18 Awọn enia na, awọn olori Gileadi si
wi fun ara wọn pe, Ọkọnrin wo ni yio
bẹ̀rẹsi bá awọn ọmọ Ammoni jà? on na ni
yio ṣe olori gbogbo awọn ara Gileadi.

## ORI 11.

JEFTA ara Gileadi si jẹ́ akọni ọkọnrin,
on si jẹ́ ọmọ panṣaga obirin kan:
Gileadi si bi Jefta.
2 Aya Gileadi si bi awọn ọmọkọnrin fun
u; nigbati awọn ọmọ aya na si dàgba,
nwọn si lé Jefta jade, nwọn si wi fun u pe,
Iwọ ki yio jogún ni ile baba wa; nitoripe
ọmọ ajeji obirin ni iwọ iṣe.
3 Nigbana ni Jefta sá kuro lọdọ awọn
arakọnrin rẹ̀, on si joko ni ile Tobu: awọn
enia lasan si kó ara wọn jọ sọdọ Jefta,
nwọn si bá a jade lọ,
4 O si ṣe lẹhin ijọ́ melokan, awọn ọmọ
Ammoni bá Israeli jagun.
5 O si ṣe nigbati awọn Ammoni bá
Israeli jagun, awọn àgba Gileadi si lọ mú
Jefta lati ilẹ Tobu wa.
6 Nwọn si wi fun Jefta pe, Wá, jẹ́ olori
wa, ki awa ki o le bá awọn ọmọ Ammoni
jà.
7 Jefta si wi fun awọn àgba Gileadi pe,
Ẹnyin kò ha ti korira mi, ẹnyin kò ha ti
lé mi kuro ni ile baba mi? ẽ si ti ṣe ti
ẹnyin fi tọ̀ mi wá nisisiyi nigbati ẹnyin wà
ninu ipọnju?
8 Awọn àgba Gileadi si wi fun Jefta pe,
Nitorina li awa ṣe pada tọ̀ ọ nisisiyi, ki
iwọ ki o le bá wa lọ, ki o si bá awọn ọmọ
Ammoni jà, ki o si jẹ́ olori wa ati ti gbogbo
awọn ara Gileadi
9 Jefta si wi fun awọn àgba Gileadi pe,
Bi ẹnyin ba mú mi pada lati bá awọn ọmọ
Ammoni jà, ti OLUWA ba si fi wọn fun mi,
emi o ha jẹ́ olori nyin bi?
10 Awọn àgba Gileadi si wi fun Jefta
pe, Jẹ ki OLUWA ki o ṣe ẹlẹri lãrin wa,
lõtọ gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ bẽli awa o ṣe.

Digitized by Google

11 Nigbana ni Jefta bá awọn àgba Gi-
leadi lọ, awọn enia na si fi i jẹ́ olori ati
balogun wọn: Jefta si sọ gbogbo ọ̀rọ rẹ̀
niwaju OLUWA ni Mispa.
12 Jefta si rán onṣẹ si ọba awọn ọmọ
Ammoni, wipe, Kili o ṣe temi tirẹ, ti iwọ
fi tọ̀ mi wá, lati jà ni ilẹ mi?
13 Ọba awọn ọmọ Ammoni si da awọn
onṣẹ Jefta lohùn pe, Nitori Israeli ti gbà
ilẹ mi, nigbati nwọn gòke ti Egipti wá,
lati Arnoni titi dé Jaboku, ati titi dé
Jordani: njẹ́ nisisiyi fi ilẹ wọnni silẹ li
alafia.
14 Jefta si tun rán onṣẹ si ọba awọn ọmọ
Ammoni:
15 O si wi fun u pe, Bayi ni Jefta wi,
Israeli kò gbà ilẹ Moabu, tabi ilẹ awọn ọmọ
Ammoni:
16 Ṣugbọn nigbati Israeli gòke ti Egipti
wá, ti nwọn si nrìn li aginjù, titi dé Okun
Pupa, ti nwọn si dé Kadeṣi;
17 Nigbana ni Israeli rán onṣẹ si ọba
Edomu, wipe, Mo bẹ̀ ọ, jẹ ki emi ki o kọja
ni ilẹ rẹ: ṣugbọn ọba Edomu kò gbọ́. Bẽ
gẹgẹ o si ranṣẹ si ọba Moabu pẹlu: ṣugbọn
kò fẹ́: Israeli si joko ni Kadeṣi.
18 Nigbana ni o rìn lãrin aginjù, o si yi
ilẹ Edomu, ati ilẹ Moabu ká, o si yọ ni ìha
ìla-õrùn ilẹ Moabu, nwọn si dó si ìha keji
Arnoni, ṣugbọn nwọn kò wá sinu àla Mo-
abu, nitoripe Arnoni ni àla Moabu.
19 Israeli si rán onṣẹ si Sihoni ọba awọn
Amori, ọba Heṣboni; Israeli si wi fun u
pe, Awa bẹ̀ ọ, jẹ ki awa ki o kọja lãrin ilẹ
rẹ si ipò mi.
20 Ṣugbọn Sihoni kò gbẹkẹle Israeli lati
kọja li àgbegbe rẹ̀; ṣugbọn Sihoni kó gbo-
gbo enia rẹ̀ jọ, nwọn si dó ni Jahasi, nwọn
si bá Israeli jagun.
21 OLUWA, Ọlọrun Israeli, si fi Sihoni,
ati gbogbo enia rẹ̀ lé Israeli lọwọ, nwọn si
kọlù wọn: Israeli si gbà gbogbo ilẹ awọn
Amori, awọn enia ilẹ na.
22 Nwọn si gbà gbogbo àgbegbe awọn
Amori, lati Arnoni titi dé Jaboku, ati lati
aginjù titi dé Jordani.
23 Njẹ, bẽni OLUWA, Ọlọrun Israeli, lé
awọn Amori kuro niwaju Israeli awọn enia
rẹ̀, iwọ o ha gbà a bi?
24 Iwọ ki yio ha gbà eyiti Kemoṣu oriṣa
rẹ fi fun ọ lati ní? Bẹ̃li ẹnikẹni ti OLUWA
Ọlọrun wa ba lé kuro niwaju wa, ilẹ wọn
ni awa o gbà.
25 Njẹ iwọ ha san jù Balaki ọmọ Sip-
poru, ọba Moabu? on ha bá Israeli ṣe gbo-
lohùn asọ̀ rí, tabi o ha bá wọn jà rí?

26 Nigbati Israeli fi joko ni Heṣboni ati
awọn ilu rẹ̀, ati ni Aroeri ati awọn ilu rẹ̀,
ati ni gbogbo awọn ilu ti o wà lọ titi li ẹba
Arnoni, li ọdunrun ọdún; ẽṣe ti ẹnyin kò
fi gbà a li akokò na?
27 Nitorina emi kò ṣẹ̀ ọ, ṣugbọn iwọ li o
ṣẹ̀ mi ni bibá mi jà: ki OLUWA, Onidajọ,
ki o ṣe idajọ li oni lãrin awọn ọmọ Israeli
ati awọn ọmọ Ammoni.
28 Ṣugbọn ọba awọn ọmọ Ammoni kò
fetisi ọ̀rọ Jefta, ti o rán si i.
29 Nigbana li ẹmi OLUWA bà lé Jefta,
on si kọja Gileadi ati Manasse, o si kọja
Mispa ti Gileadi, ati lati Mispa ti Gileadi
o si kọja lọ sọdọ awọn ọmọ Ammoni.
30 Jefta si jẹ́ ẹjẹ́ fun Ọlọrun, o si wi pe,
Bi iwọ ba jẹ fi awọn ọmọ Ammoni lé mi
lọwọ,
31 Yio si ṣe, ohunkohun ti o ba ti oju-
ilẹkun ile mi wá ipade mi, nigbati emi ba
ti ọdọ awọn Ammoni pada bọ̀ li alafia,
ti OLUWA ni yio jẹ́, emi o si fi i ru ẹbọ
sisun.
32 Jefta si kọja lọ sọdọ awọn ọmọ Am-
moni, lati bá wọn jà; OLUWA si fi nwọn lé
e lọwọ.
33 On si pa wọn ni ipakupa lati Aroeri
lọ, titi dé atiwọ̀ Miniti, ani ogún ilu, titi
o fi dé Abeli-kiramimu. Bẹ̃li a ṣẹgun
awọn ọmọ Ammoni niwaju awọn ọmọ
Israeli.
34 Jefta si bọ̀ si ile rẹ̀ ni Mispa, si kiyesi
i, ọmọbirin rẹ̀ si jade wá ipade rẹ̀ ti on ti
timbrili ati ijó: on nikan si li ọmọ rẹ̀;
lẹhin rẹ̀ kò ní ọmọkọnrin tabi ọmọbirin.
35 O si ṣe, nigbati o ri i, o fà aṣọ rẹ̀ ya,
o si wipe, Yẽ, ọmọ mi! iwọ rẹ̀ mi silẹ gidi-
gidi, iwọ si li ọkan ninu awọn ti nyọ mi
lẹnu: nitori emi ti yà ẹnu mi si OLUWA,
emi kò si le pada.
36 On si wi fun u pe, Baba mi, iwọ ti
yà ẹnu rẹ si OLUWA; ṣe si mi gẹgẹ bi eyiti
o ti ẹnu rẹ jade; niwọnbi OLUWA ti gbẹsan
fun ọ lara awọn ọtá rẹ, ani lara awọn ọmọ
Ammoni.
37 On si wi fun baba rẹ̀ pe, Jẹ ki a ṣe
nkan yi fun mi: jọwọ mi jẹ li oṣù meji, ki
emi ki o lọ ki emi si sọkalẹ sori òke, ki emi
ki o le sọkun nitori ìwa-wundia mi, emi
ati awọn ẹgbẹ mi.
38 On si wipe, Lọ. O si rán a lọ niwọn
oṣù meji: o si lọ, ati on ati awọn ẹgbẹ rẹ̀,
o si sọkun nitori ìwa-wundia rẹ̀ lori òke
wọnni.
39 O si ṣe li opin oṣù keji, o si pada wá
sọdọ baba rẹ̀, ẹniti o ṣe si i gẹgẹ bi ẹjẹ́ rẹ̀ ti

Digitized by Google

o jẹ́: on kò si mọ̀ ọkọnrin. O si di ìlana
ni Israeli pe,
40 Ki awọn ọmọbirin Israeli ma lọ li
ọdọdún lati pohunrere ọmọbirin Jefta ara
Gileadi li ọjọ́ mẹrin li ọdún.

## ORI 12.

AWỌN ọkọnrin Efraimu si kó ara wọn jọ,
nwọn si kọja si ìha ariwa; nwọn si wi
fun Jefta pe, Ẽṣe ti iwọ fi rekọja lati bá
awọn ọmọ Ammoni jà, ti iwọ kò si pè wa
ki awa ki o le bá ọ lọ? awa o fi iná kun ile
rẹ mọ́ ọ lori.
2 Jefta si wi fun wọn pe, Emi ati awọn
enia mi ti mbá awọn ọmọ Ammoni jà gidi-
gidi; nigbati emi kepè nyin, ẹnyin kò si
gbà mi li ọwọ́ wọn.
3 Nigbati emi si ri pe ẹnyin kò gbà mi,
mo fi ẹmi mi wewu, emi si rekọja sọdọ
awọn ọmọ Ammoni, OLUWA si fi nwọn lé
mi li ọwọ́: nitori kini ẹnyin ha ṣe gòke tọ̀
mi wá li oni, lati bá mi jà?
4 Nigbana ni Jefta kó gbogbo awọn
ọkọnrin Gileadi jọ, o si bá Efraimu jà:
awọn ọkọnrin Gileadi si kọlù Efraimu, ni-
toriti nwọn wipe, Isansa Efraimu li ẹnyin
ara Gileadi iṣe, lãrin Efraimu, ati lãrin
Manasse,
5 Awọn ara Gileadi si gbà ìwọdo Jor-
dani ṣiwaju Efraimu: o si ṣe, nigbati awọn
isansa Efraimu ba wipe, Jẹ ki emi ki o
rekọja, awọn ọkọnrin Gileadi a si wi fun u
pe, Efraimu ki iwọ iṣe? Bi on ba si wipe,
Ndao;
6 Nwọn a si wi fun u pe, Njẹ wi pe
Ṣibboleti; on si wi pe Sibboleti, nitoripe
on kò le pè e rere; nwọn a si mú u, nwọn
a si pa a si iwọdo Jordani: awọn ti o si
ṣubu li akokò na ninu awọn Efraimu jẹ́
ẹgbã mọkanlelogun enia.
7 Jefta si ṣe idajọ Israeli li ọdún mẹfa.
Jefta ara Gileadi si kú, a si sin i ni ilu
Gileadi kan.
8 Lẹhin rẹ̀ ni Ibsani ara Beti-lehemu ṣe
idajọ Israeli.
9 O si lí ọgbọ̀n ọmọkọnrin, ati ọgbọ̀n
ọmọbirin ti on rán lọ si ode, o si fẹ́ ọgbọ̀n
ọmọbirin lati ode wá fi fun awọn ọmọ-
kọnrin rẹ̀. On si ṣe idajọ Israeli li ọdún
meje.
10 Ibsani si kú, a si sin i ni Betilehemu.
11 Lẹhin rẹ̀ ni Eloni ti ẹ̀ya Sebuluni ṣe
idajọ Israeli; on si ṣe idajọ Israeli li ọdún
mẹwa.
12 Eloni ti ẹ̀ya Sebuluni si kú, a si sin i
ni Aijaloni ni ilẹ Sebuluni.
13 Lẹhin rẹ̀ ni Abdoni ọmọ Hilleli, ti
Piratoni, ṣe idajọ Israeli.
14 On si lí ogoji ọmọkọnrin, ati ọgbọ̀n
ọmọ ọmọ ti ngùn ãdọrin ọmọ kẹtẹkẹtẹ: on
si ṣe idajọ Israeli li ọdún mẹjọ.
15 Abdoni ọmọ Hilleli ti Piratoni si kú,
a si sin i ni Piratoni ni ilẹ Efraimu, li òke
awọn Amaleki.

## ORI 13.

AWỌN ọmọ Israeli si tun ṣe eyiti iṣe bu-
buru li oju OLUWA; OLUWA si fi wọn
lé awọn Filistini li ọwọ́ li ogoji ọdún.
2 Ọkọnrin kan ara Sora si wà, ti iṣe idile
Dani, orukọ rẹ̀ si ni Manoa, obirin rẹ̀ si
yàgan, kò si bimọ.
3 Angeli OLUWA si farahàn obirin na, o
si wi fun u pe, Sá kiyesi i, iwọ yàgan, iwọ
kò si bimọ: ṣugbọn iwọ o lóyun, iwọ o si
bi ọmọkọnrin kan.
4 Njẹ nitorina kiyesara, emi bẹ̀ ọ, máṣe
mu ọti-waini tabi ọti lile, má si ṣe jẹ ohun
aimọ́ kan:
5 Nitori kiyesi i, iwọ o lóyun, iwọ o si
bi ọmọkọnrin kan; ki abẹ ki o má ṣe kàn
a lori: nitori Nasiri Ọlọrun li ọmọ na o jẹ́
lati inu wá: on o bẹ̀rẹsi gbà Israeli li ọwọ́
awọn Filistini.
6 Nigbana obirin na wá, o si rò fun ọkọ
rẹ̀, wipe, Enia Ọlọrun kan wá sọdọ mi, irí
rẹ̀ si dabi irí angeli Ọlọrun, o ní ẹ̀ru gidi-
gidi; ṣugbọn emi kò bilère ibiti o ti wá,
bẽli on kò si sọ orukọ rẹ̀ fun mi:
7 Ṣugbọn on sọ fun mi pe, Kiyesi i, iwọ
o lóyun, iwọ o si bi ọmọkọnrin kan; nito-
rina má ṣe mu ọti-waini tabi ọti lile, bẽni
ki o má ṣe jẹ ohun aimọ́ kan: nitori Nasiri
Ọlọrun li ọmọ na o jẹ́ lati inu wá titi di ọjọ́
ikú rẹ̀.
8 Nigbana ni Manoa bẹ̀ OLUWA, o si
wipe, OLUWA, emi bẹ̀ ọ, jẹ ki enia Ọlọrun,
ti iwọ rán tun tọ̀ wa wá, ki o le kọ́ wa li
ohun ti awa o ṣe si ọmọ na ti a o bi.
9 Ọlọrun si gbọ ohùn Manoa; angeli
Ọlọrun na si tun tọ̀ obirin na wá, bi on ti
joko ninu oko; ṣugbọn Manoa ọkọ rẹ̀ kò sí
nibẹ̀ pẹlu rẹ̀.
10 Obirin na si yara kánkán, o si sure,
o si sọ fun ọkọ rẹ̀, o si wi fun u pe, Kiyesi
i, ọkọnrin ti o tọ̀ mi wá ni ijelo farahàn
mi.
11 Manoa si dide, o si tẹle aya rẹ̀, o si
wá sọdọ ọkọnrin na, o si bi i pe, Iwọ li
ọkọnrin na ti o bá obirin na sọrọ? On si
wipe, Emi ni.

Digitized by Google

12 Manoa si wipe, Njẹ ki ọ̀rọ rẹ ki o ṣẹ:
ìwa ọmọ na yio ti jẹ́, iṣẹ rẹ̀ yio ti jẹ́?
13 Angeli OLUWA si wi fun Manoa pe,
Ni gbogbo eyiti mo sọ fun obirin na ni ki
o kiyesi.
14 Ki o má ṣe jẹ ohun kan ti o ti inu
àjara wá, ki o má ṣe mu ọti-waini tabi ọti
lile, bẽni kò gbọdọ jẹ ohun aimọ́ kan;
gbogbo eyiti mo palaṣẹ fun u ni ki o
kiyesi.
15 Manoa si wi fun angeli OLUWA na pe,
Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki awa ki o da ọ duro, titi awa
o si fi pèse ọmọ ewurẹ kan fun ọ.
16 Angeli OLUWA na si wi fun Manoa
pe, Bi iwọ tilẹ da mi duro, emi ki yio jẹ
ninu àkara rẹ: bi iwọ o ba si ru ẹbọ sisun
kan, OLUWA ni ki iwọ ki o ru u si. Nitori
Manoa kò mọ̀ pe angeli OLUWA ni iṣe.
17 Manoa si wi fun angeli OLUWA na pe,
Orukọ rẹ, nitori nigbati ọ̀rọ rẹ ba ṣẹ ki awa
ki o le bọlá fun ọ?
18 Angeli OLUWA na si wi fun u pe, Ẽṣe
ti iwọ fi mbère orukọ mi, kiyesi i, Iyanu
ni.
19 Manoa si mú ọmọ ewurẹ kan pẹlu ẹbọ
ohunjijẹ, o si ru u lori apata kan si OLUWA:
angeli na si ṣe ohun iyanu, Manoa ati obirin
rẹ̀ si nwò o.
20 O si ṣe, ti ọwọ́-iná na nlọ soke ọrun
lati ibi-pẹpẹ na wá, angeli OLUWA na si
gòke ninu ọwọ́-iná ti o ti ibi-pẹpẹ jade wá.
Manoa ati aya rẹ̀ si nwò o; nwọn si doju-
bolẹ.
21 Ṣugbọn angeli OLUWA na kò si tun
farahàn fun Manoa tabi aya rẹ̀ mọ́. Nigba-
na ni Manoa to wa mọ̀ pe, angeli OLUWA
ni iṣe.
22 Manoa si wi fun aya rẹ̀ pe, Kikú li
awa o kú yi, nitoriti awa ti ri Ọlọrun.
23 Aya rẹ̀ si wi fun u pe, Ibaṣepe o wù
OLUWA lati pa wa, on kì ba ti gbà ẹbọ si-
sun ati ẹbọ ohunjijẹ li ọwọ́ wa, bẽli on kì
ba ti fi gbogbo nkan wọnyi hàn wa, bẽli on
kì ba ti sọ̀rọ irú nkan wọnyi fun wa li
akokò yi.
24 Obirin na si bi ọmọkọnrin kan, o si
sọ orukọ rẹ̀ ni Samsoni: ọmọ na si dàgba,
OLUWA si bukún u.
25 Ẹmi OLUWA si bẹ̀rẹsi ṣiṣẹ ninu rẹ̀
ni Mahane-dani, li agbedemeji Sora ati
Eṣtaolu.

## ORI 14.

SAMSONI si sọkalẹ lọ si Timna, o si ri
obirin kan ni Timna ọkan ninu awọn
ọmọbirin awọn Filistini.
2 O si gòke wá, o si sọ fun baba on iya
rẹ̀, o si wipe, Emi ri obirin kan ni Timna
ninu awọn ọmọbirin awọn Filistini: njẹ
nitorina ẹ fẹ́ ẹ fun mi li aya.
3 Nigbana ni baba on iya rẹ̀ wi fun u
pe, Kò sí obirin kan ninu awọn ọmọbirin
awọn arakọnrin rẹ, tabi ninu gbogbo awọn
enia mi, ti iwọ fi nlọ ní obirin ninu awọn
alaikọlà Filistini? Samsoni si wi fun baba
rẹ̀ pe, Fẹ́ ẹ fun mi; nitoripe o wù mi gidi-
gidi.
4 Ṣugbọn baba ati iya rẹ̀ kò mọ̀ pe ati
ọwọ́ OLUWA wá ni, nitoripe on nwá ọ̀na
lati bá awọn Filistini jà. Nitoripe li ako-
kò na awọn Filistini li alaṣẹ ni Israeli.
5 Nigbana ni Samsoni sọkalẹ lọ si Tim-
na, ati baba rẹ̀ ati iya rẹ̀, o si dé ibi ọgbà-
àjara ti o wà ni Timna: si kiyesi i, ẹgbọrọ
kiniun kan nke ramuramu si i.
6 Ẹmi OLUWA si bà lé e, o si fà a ya bi
iba ti fà ọmọ-ewurẹ ya, bẽni kò sí nkan li
ọwọ́ rẹ̀: on kò si sọ fun baba tabi iya rẹ̀ li
ohun ti o ṣe.
7 On si sọkalẹ lọ, o si bá obirin na sọ̀rọ;
on si wù Samsoni gidigidi.
8 Lẹhin ijọ́ melokan o si tun pada lati
mú obirin na, o si yà lati wò okú kiniun
na: si kiyesi i, ìṣu-ọ̀pọ oyin wà ninu okú
kiniun na, ati oyin.
9 O si bù ninu rẹ̀ si ọwọ́ rẹ̀, o si njẹ ẹ li
ajẹrìn, titi o si fi dé ọdọ baba ati iya rẹ̀, o
si fi fun wọn, nwọn si jẹ: ṣugbọn on kò sọ
fun wọn pe ninu okú kiniun li on ti mú
oyin na wá.
10 Baba rẹ̀ si sọkalẹ tọ̀ obirin na lọ:
Samsoni si sè àse nibẹ̀; nitoripe bẽli awọn
ọmọkọnrin ima ṣe.
11 O si ṣe nigbati nwọn ri i, nwọn si mú
ọgbọ̀n enia wa bá a kẹgbẹ.
12 Samsoni si wi fun wọn pe, Ẹ jẹ ki
npa alọ́ kan fun nyin: bi ẹnyin ba le já a
fun mi titi ijọ́ meje àse yi, ti ẹnyin ba si
mọ̀ ọ, njẹ emi o fun nyin li ọgbọ̀n ẹ̀wu, ati
ọgbọ̀n ìparọ aṣọ:
13 Ṣugbọn bi ẹnyin kò ba le já a fun mi,
njẹ ẹnyin o fun mi li ọgbọ̀n ẹ̀wu, ati ọgbọ̀n
ìparọ aṣọ. Nwọn si wi fun u pe, Pa alọ́ rẹ
ki awa ki o gbọ́.
14 O si wi fun wọn pe, Lati inu ọjẹun li
onjẹ ti jade wá, ati lati inu alagbara li adùn
ti jade wá. Nwọn kò si le já alọ́ na nìwọn
ijọ́ mẹta.
15 O si ṣe ni ijọ́ keje, nwọn si wi fun
obirin Samsoni pe, Tàn ọkọ rẹ, ki o le já
alọ́ na fun wa, ki awa ki o má ba fi iná
sun iwọ ati ile baba rẹ: ẹnyin pè wa ki

Digitized by Google

ẹnyin ki o le gbà ohun-iní wa ni? bẽ ha kọ?

16 Obirin Samsoni si sọkun niwaju rẹ̀, o si wipe, Iwọ korira mi ni, iwọ kò si fẹràn mi: iwọ pa aló kan fun awọn ọmọ enia mi, iwọ kò si já a fun mi. On si wi fun u pe, Kiyesi i, emi kò já a fun baba ati iya mi, emi o ha já a fun ọ bi?

17 O si sọkun niwaju rẹ̀ titi ijọ́ meje ti àse na gbà: O si ṣe ni ijọ́ keje, o si já a fun u, nitoripe on ṣe e li aisimi pupọ̀, on si já aló na fun awọn ọmọ enia rẹ̀.

18 Awọn ọkọnrin ilunla na si wi fun u ni ijọ́ keje ki õrùn ki o to wọ̀ pe, Kili o dùn jù oyin lọ? kili o si lí agbara jù kiniun lọ? On si wi fun wọn pe, Ibaṣepe ẹnyin kò fi ẹgbọrọ abomalu mi tulẹ, ẹnyin kì ba ti mọ̀ aló mi.

19 Ẹmi OLUWA si bà lé e, o si sọkalẹ lọ si Aṣkeloni, o si pa ọgbọ̀n ọkọnrin ninu wọn, o si kó ẹrù wọn, o si fi ìparọ aṣọ fun awọn ti o já aló na. Ibinu rẹ̀ si rú, on si gòke lọ si ile baba rẹ̀.

20 Nwọn si fi obirin Samsoni fun ọkan ninu awọn ẹgbẹ rẹ̀, ti iṣe ọrẹ́ rẹ̀.

## ORI 15.

O SI ṣe ni ọ̀sa kan, li akokò ikore alikama, Samsoni mú ọmọ ewurẹ kan lọ bẹ̀ aya rẹ̀ wò; on si wipe, Emi o wọle tọ̀ aya mi lọ ni iyẹwu. Ṣugbọn baba obirin rẹ̀ kò jẹ ki o wọle.

2 Baba aya rẹ̀ si wipe, Nitõtọ emi ṣebi iwọ korira rẹ̀ patapata ni; nitorina ni mo ṣe fi i fun ẹgbẹ rẹ: aburò rẹ̀ kò ha ṣe arẹwà enia jù on lọ? mo bẹ̀ ọ, mú u dipò rẹ̀.

3 Samsoni si wi fun wọn pe, Nisisiyi emi o jẹ́ alaijẹbi lọdọ awọn Filistini, bi mo tilẹ ṣe wọn ni ibi.

4 Samsoni si lọ o mú ọdunrun kọ̀lọkọlọ, o si mú ètufu, o si fi ìru wọn kò ìru, o si fi ètufu kan sãrin ìru meji.

5 Nigbati o si ti fi iná si ètufu na, o jọwọ wọn lọ sinu oko-ọkà awọn Filistini, o si kun ati eyiti a dì ni ití, ati eyiti o wà li oró, ati ọgbà-olifi pẹlu.

6 Nigbana li awọn Filistini wipe, Tani ṣe eyi? Nwọn si dahùn pe, Samsoni, ana ara Timna ni, nitoriti o gbà obirin rẹ̀, o si fi i fun ẹgbẹ rẹ̀. Awọn Filistini si gòke wá, nwọn si fi iná sun obirin na ati baba rẹ̀.

7 Samsoni si wi fun wọn pe, Bi ẹnyin ba ṣe irú eyi, dajudaju emi o gbẹsan lara nyin, lẹhin na emi o si dẹkun.

8 On si kọlù wọn, o si pa wọn ni ipakupa: o si sọkalẹ o si joko ni palapala apata Etamu.

9 Nigbana li awọn Filistini gòke lọ, nwọn si dótì Juda, nwọn si tẹ́ ara wọn lọ bẹrẹ ni Lehi.

10 Awọn ọkọnrin Juda si wipe, Nitori kili ẹnyin ṣe gòke tọ̀ wa wá? Nwọn si dahùn wipe, Lati dè Samsoni li awa ṣe wá, lati ṣe si i gẹgẹ bi on ti ṣe si wa.

11 Nigbana li ẹgbẹdogun ọkọnrin Juda sọkalẹ lọ si palapala apata Etamu, nwọn si wi fun Samsoni, pe, Iwọ kò mọ̀ pe awọn Filistini li alaṣẹ lori wa? kili eyiti iwọ ṣe si wa yi? On si wi fun wọn pe, Gẹgẹ bi nwọn ti ṣe si mi, bẹ̃li emi ṣe si wọn.

12 Nwọn si wi fun u pe, Awa sọkalẹ wá lati dè ọ, ki awa ki o le fi ọ lé awọn Filistini lọwọ. Samsoni si wi fun wọn pe, Ẹ bura fun mi, pe ẹnyin tikara nyin ki yio pa mi.

13 Nwọn si wi fun u pe, Ndao; didè li awa o dè ọ, a o si fi ọ lé wọn lọwọ: ṣugbọn niti pipa awa ki yio pa ọ. Nwọn si fi okùn titun meji dè e, nwọn si mú u gòke lati ibi apata na wá.

14 Nigbati o dé Lehi, awọn Filistini hó bò o: ẹmi OLUWA si bà lé e, okùn ti o si wà li apa rẹ̀ si wa dabi okùn-ọ̀gbọ ti o ti jóna, ìde rẹ̀ si tú kuro li ọwọ́ rẹ̀.

15 O si ri pari-ẹrẹkẹ kẹtẹkẹtẹ titun kan, o si nà ọwọ́ rẹ̀, o si mú u, o si fi i pa ẹgbẹrun ọkọnrin.

16 Samsoni si wipe, Pari-ẹrẹkẹ kan ni mo fi pa òkiti kan, òkiti meji; pari-ẹrẹkẹ kẹtẹkẹtẹ kan ni mo fi pa ẹgbẹrun ọkọnrin.

17 O si ṣe, nigbati o pari ọ̀rọ sisọ tán, o sọ pari-ẹrẹkẹ na nú, o si pè ibẹ̀ na ni Ramati-lehi.

18 Ongbẹ si ngbẹ ẹ gidigidi, o si kepè OLUWA, wipe, Iwọ ti fi ìgbala nla yi lé ọmọ-ọdọ rẹ lọwọ: nisisiyi emi o kú nitori ongbẹ, emi o si bọ́ si ọwọ́ awọn alaikọlà.

19 Ṣugbọn Ọlọrun si là ibi kòto kan ti o wà ni Lehi, nibẹ̀ li omi si sun jade; nigbati on si mu u tán ẹmi rẹ̀ si tun pada, o si sọji: nitorina ni a ṣe pè orukọ ibẹ̀ na ni Eni-hakkore, ti o wà ni Lehi, titi o fi di oni-oloni.

20 On si ṣe idajọ Israeli li ọjọ́ awọn Filistini li ogún ọdún.

## ORI 16.

SAMSONI si lọ si Gasa, o si ri obirin panṣaga kan nibẹ̀, o si wọle tọ̀ ọ.

2 Awọn ara Gasa si gbọ́ pe, Samsoni wá si ihin. Nwọn si yi i ká, nwọn lumọ́ ni

Digitized by Google

gbogbo oru na li ẹnu-bode ilu na, nwọn si
dakẹ jẹ ni gbogbo oru na, wipe, Li owurọ̀
nigbati ilẹ ba mọ́, li awa o pa a.
3 Samsoni si dubulẹ titi o fi di ãrin ọgan-
jọ, o si dide lãrin ọganjọ, o si gbé ilẹkun-
ibode ilu na, ati opó mejeji, o si fà wọn tu
pẹlu idabu-ẹ̀kun, o gbé wọn lé ejika rẹ̀, o
si rù wọn lọ si ori òke kan ti o wà niwaju
Hebroni.
4 O si ṣe lẹhin eyinì, o si fẹ́ obirin kan
li afonifoji Soreki, a si ma pè orukọ́ rẹ̀ ni
Delila.
5 Awọn ijoye Filistini tọ̀ ọ wá, nwọn si
wi fun u pe, Tàn a, ki o si mọ̀ ibiti agbara
nla rẹ̀ gbé wà, ati bi awa o ti ṣe le bori rẹ̀,
ki awa ki o le dè e lati jẹ ẹ niyà: olukulu-
ku wa yio si fun ọ ni ẹdẹgbẹfa owo fadakà.
6 Delila si wi fun Samsoni pe, Emi bẹ̀ ọ,
wi fun mi, nibo li agbara nla rẹ gbé wà, ati
kili a le fi dè ọ lati jẹ ọ niyà.
7 Samsoni si wi fun u pe, Bi a ba fi okùn
tutù meje ti a kò ságbẹ dè mi, nigbana li
emi o di alailera, emi o si dabi ọkọnrin
miran.
8 Nigbana li awọn ijoye Filistini mú okùn
tutù meje tọ̀ ọ wá ti a kò ságbẹ, o si fi okùn
wọnni dè e.
9 Obirin na si ní awọn kan, ti nwọn
lumọ́ ninu yará. On si wi fun u pe, Awọn
Filistini dé, Samsoni. On si já okùn na,
gẹgẹ bi owú ti ijá nigbati o ba kan iná.
Bẹ̃li a kò mọ̀ agbara rẹ̀.
10 Delila si wi fun Samsoni pe, Kiyesi i,
iwọ tàn mi jẹ, o si purọ́ fun mi: wi fun
mi, emi bẹ̀ ọ, kili a le fi dè ọ.
11 On si wi fun u pe, Bi nwọn ba le fi
okùn titun ti a kò ti lò rí dè mi le koko,
nigbana li emi o di alailera, emi o si dabi
ọkọnrin miran.
12 Bẹ̃ni Delila mú okùn titun, o si fi dè
e, o si wi fun u pe, Awọn Filistini dé,
Samsoni. Awọn ti o lumọ́ dè e wà ninu
yará. On si já wọn kuro li apa rẹ̀ bi owu.
13 Delila si wi fun Samsoni pe, Titi di
isisiyi iwọ ntàn mi ni, iwọ si npurọ́ fun mi:
sọ fun mi, kili a le fi dè ọ. On si wi fun
u pe, Bi iwọ ba wun ìdi irun meje ti o wà
li ori mi.
14 On si fi ẽkàn dè e, o si wi fun u pe,
Awọn Filistini dé, Samsoni. O si jí kuro
li oju orun rẹ̀, o si fà ẽkàn ìti na pẹlu iwu-
nṣọ rẹ̀ lọ.
15 On si wi fun u pe, Iwọ ha ti ṣe wipe,
Emi fẹ́ ọ, nigbati ọkàn rẹ kò ṣedede pẹlu
mi? iwọ ti tàn mi ni ìgba mẹta yi, iwọ kò
si sọ ibiti agbara nla rẹ gbé wà fun mi.
16 O si ṣe, nigbati o fi ọ̀rọ rẹ̀ rọ̀ ọ li ojo-
jumọ́, ti o si ṣe e laisimi, tobẹ̃ ti sũru fi tan
ọkàn rẹ̀ dé ikú.
17 Li on si sọ gbogbo eyiti o wá li ọkàn
rẹ̀ fun u, o si wi fun u pe, Abẹ kò kàn ori
mi rí; nitoripe Nasiri Ọlọrun li emi iṣe
lati inu iya mi wá: bi a ba fá ori mi, ni-
gbana li agbara mi yio lọ kuro lọdọ mi, emi
o si di alailera, emi o si dabi ọkọnrin
miran.
18 Nigbati Delila ri pe, o sọ gbogbo
ọkàn rẹ̀ fun u, o si ranṣẹ pè awọn ijoye
Filistini, wipe, Ẹ gòke wá lẹkan yi, nito-
riti o sọ gbogbo ọkàn rẹ̀ fun mi. Nigbana
li awọn ijoye Filistini wá sọdọ rẹ̀, nwọn si
mú owo li ọwọ́ wọn.
19 O si mú ki o sùn li ẽkun rẹ̀: o si pè
ọkọnrin kan, o si mu ki o fá ìdi irun me-
jeje ori rẹ̀; on si bẹ̀rẹsi pọ́n ọ loju, agbara
rẹ̀ si ti lọ kuro lọdọ rẹ̀.
20 On si wipe, Awọn Filistini dé, Sam-
soni. O si jí kuro li oju orun rẹ̀, o si wipe,
Emi o jade lọ bi ìgba iṣaju, ki emi ki o si
gbọ̀n ara mi. On kò si mọ̀ pe Oluwa ti
kuro lọdọ on.
21 Awọn Filistini sì mú u, nwọn si yọ ọ
li oju mejeji; nwọn si mú u sọkalẹ wá si
Gasa, nwọn si fi ṣẹkẹṣẹkẹ idẹ dè e: on si
nlọlọ ni ile-tubu.
22 Ṣugbọn irun ori rẹ̀ bẹ̀rẹsi hù lẹhin
igbati a ti fá a tán.
23 Nigbana ni awọn ijoye Filistini kó
ara wọn jọ lati ru ẹbọ nla kan si Dagoni
oriṣa wọn, ati lati yọ̀: nitoriti nwọn wipe,
Oriṣa wa fi Samsoni ọtá wa lé wa lọwọ.
24 Nigbati awọn enia si ri i, nwọn fi
iyìn fun oriṣa wọn: nitoriti nwọn wipe,
Oriṣa wa fi ọtá wa lé wa lọwọ, ẹniti npa
ilẹ wa run, ti o si pa ọ̀pọlọpọ enia ninu
wa.
25 O si ṣe, nigbati inu wọn dùn, ni
nwọn wipe, Ẹ pè Samsoni, ki o wa ṣiré fun
wa. Nwọn si pè Samsoni lati inu ile-itubu
wá; o si ṣiré niwaju wọn: nwọn si mu u
duro lãrin ọwọ̀n meji.
26 Samsoni si wi fun ọmọkọnrin ti o di
ọwọ́ rẹ̀ mú pe, Jẹ ki emi ki o fọwọbà awọn
ọwọ̀n ti ile joko lé, ki emi ki o le faratì
wọn.
27 Njẹ ile na kún fun ọkọnrin ati obirin;
gbogbo awọn ijoye Filistini si wà nibẹ̀;
awọn ti o si wà lori orule, ati ọkọnrin ati
obirin, o to ìwọn ẹgbẹdogun enia, ti nwo-
ran Samsoni nigbati o nṣiré.
28 Samsoni si kepè Oluwa, o si wipe,
Oluwa Ọlọrun, emi bẹ̀ ọ, ranti mi, ki o si

Digitized by Google

jọ̃ fun mi li agbara lẹ̃kanṣoṣo yi, Ọlọrun, ki emi ki o le gbẹsan lẹ̃kan lara awọn Filistini nitori oju mi mejeji.
29 Samsoni si dì ọwọ̀n ãrin mejeji na mú lori eyiti ile na joko, o si faratì wọn, o fi ọwọ́ ọtún rẹ̀ mú kan, o si fi ọwọ́ òsi rẹ̀ mú ekeji.
30 Samsoni si wipe, Jẹ ki nkú pẹlu awọn Filistini. O si fi gbogbo agbara rẹ̀ bẹrẹ; ile na si wó lù awọn ijoye wọnni, ati gbogbo enia ti o wà ninu rẹ̀. Bẽli awọn okú ti o pa ni ikú rẹ̀, pọjù awọn ti o pa li aiye rẹ̀ lọ.
31 Nigbana li awọn arakọnrin rẹ̀ ati gbogbo idile baba rẹ̀ sọkalẹ wá, nwọn si gbé e gòke, nwọn si sin i lãrin Sora on Eṣtaolu ni ibojì Manoa baba rẹ̀. O si ṣe idajọ Israeli li ogún ọdún.

## ORI 17.

ỌKỌNRIN kan si wà ni ilẹ òke Efraimu, orukọ ẹniti ijẹ Mika.
2 On si wi fun iya rẹ̀ pe, Ẹdẹgbẹfa owo fadakà ti a kólọ lọwọ rẹ, nitori eyiti iwọ gegún, ti iwọ si sọ̀rọ rẹ̀ li etí mi pẹlu, kiyesi i, fadakà na wà li ọwọ́ mi; emi li o kó o. Iya rẹ̀ si wipe, Alabukún ti OLUWA ni ọmọ mi.
3 On si kó ẹdẹgbẹfa owo fadakà na fun iya rẹ̀ pada, iya rẹ̀ si wipe, Patapata ni mo yà fadakà wọnni sọ̀tọ fun OLUWA kuro li ọwọ́ mi, fun ọmọ mi, lati fi ṣe ere fifin ati ere didà: njẹ nitorina emi o fun ọ pada.
4 Ṣugbọn o kó owo na pada fun iya rẹ̀; iya rẹ̀ si mú igba owo fadakà, o si fi i fun onişọnà, ẹniti o fi i ṣe ere fifin ati ere didà: o si wà ni ile Mika.
5 Ọkọnrin na Mika si ní ile-oriṣa kan, o si ṣe efodu, ati terafimu, o si yà ọkan ninu awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin sọtọ̀, ẹniti o si wa di alufa rẹ̀.
6 Li ọjọ́ wọnni ọba kan kò sí ni Israeli: olukuluku enia nṣe eyiti o tọ́ li oju ara rẹ̀.
7 Ọmọkọnrin kan si ti Beti-lehemu-juda wá, ti iṣe idile Juda, ẹniti iṣe ẹ̀ya Lefi, on si ṣe atipo nibẹ̀.
8 Ọkọnrin na si ti ilu Beti-lehemu-juda lọ, lati ṣe atipo nibikibi ti o ba ri: on si dé ilẹ òke Efraimu si ile Mika, bi o ti nlọ.
9 Mika si wi fun u pe, Nibo ni iwọ ti wá? On si wi fun u pe, Ẹya Lefi ti Beti-lehemu-juda li emi iṣe, emi si nlọ ṣe atipo nibikibi ti emi ba ri.
10 Mika si wi fun u pe, Bá mi joko, ki iwọ ki o ma ṣe baba ati alufa fun mi, emi o ma fi owo fadakà mẹwa fun ọ li ọdún, adápe aṣọ kan, ati onjẹ rẹ. Bẽni ọmọ Lefi na si wọle.
11 O si rọ̀ ọmọ Lefi na lọrùn lati bá ọkọnrin na joko; ọmọkọnrin na si wà lọdọ rẹ̀ bi ọkan ninu awọn ọmọ rẹ̀.
12 Mika si yà ọmọ Lefi na sọ̀tọ, ọmọkọnrin na si wa di alufa rẹ̀, o si wà ninu ilé Mika.
13 Mika si wipe, Njẹ nisisiyi li emi tó mọ̀ pe, OLUWA yio ṣe mi li ore, nitoriti emi li ọmọ Lefi kan li alufa mi.

## ORI 18.

LI ọjọ́ wọnni ọba kan kò sí ni Israeli: ati li ọjọ́ wọnni ẹ̀ya Dani nwá ilẹ-iní kan lati joko si; nitoripe titi o fi di ọjọ́ na, ilẹ-iní wọn lãrin awọn ẹ̀ya Israeli kò ti ibọ́ si ọwọ́ wọn.
2 Awọn ọmọ Dani si rán ọkọnrin marun ninu idile wọn lati àgbegbe wọn wá, awọn ọkọnrin alagbara, lati Sora, ati Eṣtaolu lọ, lati lọ ṣamí ilẹ na, ati lati rìn i wò; nwọn si wi fun wọn pe, Ẹ lọ rìn ilẹ na wò: nwọn si dé ilẹ òke Efraimu, si ile Mika, nwọn si wọ̀ nibẹ̀.
3 Nigbati nwọn wà leti ile Mika, nwọn si mọ̀ ohùn ọmọkọnrin Lefi na: nwọn si wọ̀ inu ile na, nwọn si wi fun u pe, Tali o mú ọ wá ihin yi? kini iwọ si nṣe ni ihinyi? kini iwọ si ní nihin?
4 On si wi fun wọn pe, Bayibayi ni Mika ṣe fun mi, o gbà mi si iṣẹ, alufa rẹ̀ li emi si iṣe.
5 Nwọn si wi fun u pe, Bère lọdọ Ọlọrun, awa bẹ̀ ọ, ki awa ki o le mọ̀ bi ọ̀na wa ti awa nlọ yio jasi rere.
6 Alufa na si wi fun wọn pe, Ẹ ma lọ li alafia: ọ̀na nyin ti ẹnyin nlọ mbẹ niwaju OLUWA.
7 Nigbana li awọn ọkọnrin mararun na lọ, nwọn si dé Laiṣi, nwọn si ri awọn enia ti o wà ninu rẹ̀, bi nwọn ti joko laibẹ̀ru, gẹgẹ bi iṣe awọn ara Sidoni, ni ijokojẹ ati laibẹ̀ru; kò si sí olori kan ni ilẹ na, ti iba mu oju tì wọn li ohunkohun, nwọn si jìna si awọn ara Sidoni, nwọn kò si ba ẹnikẹni ṣe.
8 Nwọn si wá sọdọ awọn arakọnrin wọn si Sora ati Eṣtaolu: awọn arakọnrin wọn si wi fun wọn pe, Kili ẹnyin wi?
9 Nwọn si wipe, Ẹ dide, ki awa ki o tọ̀ wọn: nitoriti awa ri ilẹ na, si kiyesi i, o dara gidigidi: ẹ dakẹ ni? ẹ máṣe lọra lati lọ, ati lati wọ̀ ibẹ̀ lọ gbà ilẹ na.
10 Nigbati ẹnyin ba lọ, ẹnyin o dé ọdọ awọn enia ti o wà laibẹ̀ru, ilẹ na si tobi:

Digitized by Google

nitoriti Ọlọrun ti fi i lé nyin lọwọ; ibiti kò
sí ainí ohunkohun ti mbẹ'lori ilẹ.
11 Awọn enia idile Dani si ti ibẹ̀ lọ, lati
Sora ati lati Eṣtaolu, ẹgbẹta ọkọnrin ti o
hamọra ogun;
12 Nwọn si gòke lọ, nwọn si dó si Kiri-
ati-jearimu, ni Juda: nitorina ni nwọn ṣe
npè ibẹ̀ na ni Mahane-dani titi o fi di oni
yi: kiyesi i, o wà lẹhin Kiriati-jearimu.
13 Nwọn si kọja lati ibẹ̀ lọ si ilẹ òke
Efraimu, nwọn si wá si ile Mika.
14 Nigbana li awọn ọkọnrin marun ti a
rán ti o ti lọ ṣamí ilẹ Laiṣi dahùn, nwọn si
wi fun awọn arakọnrin wọn pe, Ẹ mọ̀ pe
efodu kan wà ninu ile wọnyi, ati terafimu,
ati ere fifin, ati ere didà? njẹ nitorina ẹ rò
eyiti ẹnyin o ṣe.
15 Nwọn si yà sibẹ̀, nwọn si wá si ile
ọmọkọnrin Lefi na, ani si ile Mika, nwọn
si bère alafia rẹ̀.
16 Awọn ẹgbẹta ọkọnrin ti o hamọra
ogun ninu awọn ọmọ Dani, duro li ẹnu-
ọ̀na.
17 Awọn ọkọnrin marun ti o ti lọ iṣamí
ilẹ na gòke lọ, nwọn si wá si ibẹ̀ na, nwọn
si kó ere fifin, ati efodu, ati terafimu, ati
ere didà na: alufa na si duro li ẹnu-ọ̀na
pẹlu awọn ẹgbẹta ọkọnrin ti o hamọra ogun.
18 Nigbati awọn wọnyi si wọ̀ ile Mika
lọ, nwọn si mú ere fifin, efodu, ati terafimu,
ati ere didà na, nigbana li alufa na wi fun
wọn pe, Kili ẹnyin nṣe yi?
19 Nwọn si wi fun u pe, Dakẹ, fi ọwọ́ rẹ
lé ẹnu rẹ, ki o si ma bá wa lọ, ki o si ma
ṣe baba fun wa ati alufa: o ha san fun ọ
lati ṣe alufa fun ile ọkọnrin kan, tabi ki
iwọ ki o ṣe alufa fun ẹ̀ya ati idile kan ni
Israeli?
20 Inu alufa na si dùn, o si mú efodi,
ati terafimu, ati ere fifin, o si bọ̀ sãrin
awọn enia na.
21 Bẹ̃ni nwọn yipada nwọn si lọ, nwọn
tì awọn ọmọ kekere ati ẹran ati ẹrù siwaju
wọn.
22 Nigbati nwọn si lọ jìna si ile Mika,
awọn ọkọnrin ti o wà ninu ile wọnni ti o
sunmọ ile Mika kó ara wọn jọ, nwọn si lé
awọn ọmọ Dani bá.
23 Nwọn si kọ si awọn ọmọ Dani.
Nwọn si yi oju wọn pada, nwọn wi fun
Mika pe, Kili o ṣe ọ, ti iwọ fi kó irú ẹgbẹ
bẹ̃ lẹhin wá?
24 On si wipe, Ẹnyin kó awọn oriṣa mi
ti mo ṣe lọ, ẹ si mú alufa, ẹ si lọ, kini mo
si tun ní? kili eyiti ẹnyin wi fun mi pe,
Kili o ṣe ọ?
25 Awọn ọmọ Dani si wi fun u pe, Máṣe
jẹ ki a gbọ́ ohùn rẹ lãrin wa, ki awọn oní-
nuṣùṣu ki o má ba kọlù nyin, iwọ a si sọ
ẹmi rẹ nù, ati ẹmi awọn ara ile rẹ.
26 Awọn ọmọ Dani si ba ọ̀na wọn lọ:
nigbati Mika si ri i pe, nwọn lagbara jù on
lọ, on si yipada, o si pada lọ sinu ile rẹ̀.
27 Nwọn si kó awọn nkan wọnni ti
Mika ṣe, ati alufa ti o ní, nwọn si wá si
Laiṣi sọdọ awọn enia ti o wà ni ìjokojẹ
ati laibẹ̀ru, nwọn si fi oju idà kọlù wọn,
nwọn si fi iná kun ilu na.
28 Kò si sí olugbala, nitoriti o jìna si
Sidoni, nwọn kò si bá ẹnikẹni ṣe; o si wà
ni afonifoji ti o wà ni Beti-rehobu. Nwọn
si kọ́ ilu na, nwọn si ngbé inu rẹ̀.
29 Nwọn si pè orukọ ilu na ni Dani,
gẹgẹ bi orukọ Dani baba wọn, ẹniti a bi
fun Israeli: ṣugbọn Laiṣi li orukọ ilu na li
atijọ rí.
30 Awọn ọmọ Dani si gbé ere fifin na
kalẹ: ati Jonatani, ọmọ Gerṣomu, ọmọ
Mose, on ati awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin li o nṣe
alufa fun ẹ̀ya Dani titi o fi di ọjọ́ ti a fi kó
ilẹ na ni igbekun lọ.
31 Nwọn si gbé ere fifin ti Mika ṣe kalẹ
ni gbogbo ọjọ́ ti ile Ọlọrun fi wà ni Ṣilo.

## ORI 19.

O SI ṣe li ọjọ́ wọnni, nigbati kò sí ọba kan
ni Israeli, ọkọnrin Lefi kan nṣe atipo
ni ìha ọhún ilẹ òke Efraimu, ẹniti ó si mú
àle kan lati Beti-lehemu-juda wá.
2 Àle rẹ̀ na si ṣe panṣaga si i, o si lọ
kuro lọdọ rẹ̀ si ile baba rẹ̀ si Beti-lehemu-
juda, o si wà ni ibẹ̀ ni ìwọn oṣù mẹrin.
3 Ọkọ rẹ̀ si dide, o si tọ̀ ọ lọ, lati tù u
ninu, ati lati mú u pada, ọmọ-ọdọ rẹ̀ si
mbẹ pẹlu rẹ̀, ati kẹtẹkẹtẹ meji: ọmọbirin
na si mú u wá sinu ile baba rẹ̀: nigbati
baba rẹ̀ si ri i, o yọ̀ lati pade rẹ̀.
4 Ana rẹ̀, baba ọmọbirin na, si da a
duro; o si bá a joko ni ijọ́ mẹta; nwọn jẹ
nwọn mu, nwọn si wọ̀ nibẹ̀.
5 O si ṣe ni ijọ́ kẹrin, nwọn jí ni kùtu-
kutu, o si dide lati lọ: baba ọmọbirin na
si wi fun ana rẹ̀ pe, Fi òkele onjẹ kan tẹlẹ
inu, lẹhin na ki ẹ ma lọ.
6 Nwọn si joko, awọn mejeji si jùmọ jẹ,
nwọn si mu: baba ọmọbirin na si wi fun
ọkọnrin na pe, Mo bẹ̀ ọ, farabalẹ, ki o si
duro li oru oni, ki o si jẹ ki inu rẹ ki o dùn.
7 Nigbati ọkọnrin na si dide lati lọ, ana
rẹ̀ si rọ̀ ọ, o si tun sùn sibẹ̀.
8 On si dide ni kùtukutu ọjọ́ karun lati
lọ, baba ọmọbirin na si wipe, Mo bẹ̀ ọ, tù



Digitized by Google

ara rẹ lara, ki ẹ si duro titi di irọlẹ; awọn
mejeji si jẹun.
9 Nigbati ọkọnrin na si dide lati lọ, on,
ati àle rẹ̀, ati ọmọ-ọdọ rẹ̀, ana rẹ̀, baba
ọmọbirin na, si wi fun u pe, Kiyesi i nisi-
siyi, ọjọ́ di aṣalẹ tán, emi bẹ̀ ọ duro li oru
yi: kiyesi i ọjọ́ lọ tán, sùn sihin, ki inu
rẹ ki o le dùn: ni kùtukutu ọla ẹ tète bọ́
si ọ̀na nyin, ki iwọ ki o le lọ ile.
10 Ọkọnrin na si kọ̀ lati sùn, o si dide o
si lọ, o si dé ọkankan Jebusi (ti iṣe Jerusa-
lemu): kẹtẹkẹtẹ meji ti a dì ni gãri wà
lọdọ rẹ̀, àle rẹ̀ pẹlu si wà lọdọ rẹ̀.
11 Nigbati nwọn si dé eti Jebusi, ọjọ́ lọ
tán; ọmọ-ọdọ na si wi fun oluwa rẹ̀ pe,
Wá, emi bẹ̀ ọ, jẹ ki a yà si ilu Jebusi yi,
ki a si wọ̀ sibẹ̀.
12 Oluwa rẹ̀ si wi fun u pe, Awa ki o yà
si ilu ajeji kan, ti ki iṣe ti awọn ọmọ Is-
raeli; awa o rekọja si Gibea.
13 On si wi fun ọmọ-ọdọ rẹ̀ pe, Wá jẹ ki
a sunmọ ọkan ninu ibi wọnyi; ki a si wọ̀
si Gibea, tabi Rama.
14 Nwọn si rekọja, nwọn lọ: õrùn si wọ̀
bá wọn leti Gibea, ti iṣe ti Benjamini.
15 Nwọn si yà si Gibea lati wọ̀ ọ, ati
lati sùn nibẹ̀: o si wọ̀ inu rẹ̀ lọ, o joko ni
igboro ilu na: nitoriti kò sí ẹnikan ti o gbà
wọn sinu ile rẹ̀ lati wọ̀.
16 Si kiyesi i, ọkọnrin arugbo kan si nti
ibi iṣẹ rẹ̀ bọ̀ lati inu oko wá li alẹ; ọkọnrin
na jẹ́ ara ilẹ òke Efraimu pẹlu, on si ṣe
atipo ni Gibea: ṣugbọn ẹ̀ya Benjamini ni
awọn ọkọnrin ibẹ̀ iṣe.
17 Nigbati o gbé oju rẹ̀ soke, o si ri èro
kan ni igboro ilu; ọkọnrin arugbo na si
wipe, Nibo ni iwọ nrè? nibo ni iwọ si ti
wá?
18 On si wi fun u pe, Awa nrekọja lati
Beti-lehemu-juda lọ si ìha ọhún ilẹ òke
Efraimu; lati ibẹ̀ li emi ti wá, emi si ti lọ
si Beti-lehemu-juda: nisisiyi emi nlọ si ile
OLUWA; kò si sí ẹnikan ti o gbà mi si ile.
19 Bẽni koriko ati ohunjijẹ mbẹ fun
awọn kẹtẹkẹtẹ wa; onjẹ ati ọti-waini si
mbẹ fun mi pẹlu, ati fun iranṣẹbirin rẹ, ati
fun ọmọkọnrin ti mbẹ lọdọ awọn iranṣẹ rẹ:
kò si sí ainí ohunkohun.
20 Ọkọnrin arugbo na si wipe, Alafia
fun ọ; bi o ti wù ki o ri, jẹ ki gbogbo ainí
rẹ ki o pọ̀ si apa ọdọ mi; ọkanṣoṣo ni,
máṣe sùn si igboro.
21 Bẽli o mú u wá sinu ile rẹ̀, o si fi
onjẹ fun awọn kẹtẹkẹtẹ: nwọn wẹ̀ ẹsẹ̀ wọn,
nwọn jẹ nwọn si mu.
22 Njẹ bi nwọn ti nṣe ariya, kiyesi i,
awọn ọkọnrin ilu na, awọn ọmọ Beliali
kan, yi ile na ká, nwọn si nlù ilẹkun;
nwọn si sọ fun bale ile na ọkọnrin arugbo
nì pe, Mú ọkọnrin ti o wọ̀ sinu ile rẹ nì
wá, ki awa ki o le mọ̀ ọ.
23 Ọkọnrin, bale ile na si jade tọ̀ wọn
lọ, o si wi fun wọn pe, Bẹ̃kọ, ẹnyin ara-
kọnrin mi, emi bẹ̀ nyin, ẹ má ṣe hùwa-
buburu; nitoriti ọkọnrin yi ti wọ̀ ile mi, ẹ
má ṣe hùwa wère yi.
24 Kiyesi i, ọmọbirin mi li eyi, wundia,
ati àle rẹ̀; awọn li emi o mú jade wá
nisisiyi, ki ẹnyin tẹ́ wọn li ogo, ki ẹnyin
ṣe si wọn bi o ti tọ́ li oju nyin: ṣugbọn
ọkọnrin yi ni ki ẹnyin má ṣe hùwa wère
yi si.
25 Ṣugbọn awọn ọkọnrin na kò fẹ́ gbọ́
tirẹ̀: ọkọnrin na si mú àle rẹ̀, o si mú u
tọ̀ wọn wá; nwọn si mọ̀ ọ, nwọn si hù u
niwakiwa ni gbogbo oru na, titi o fi di
owurọ̀: nigbati o si di afẹmọjumọ́ nwọn
jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ.
26 Nigbana li obirin na wá li afẹmọjumọ́,
o si ṣubu lulẹ li ẹnu-ilẹkun ile ọkọnrin na
nibiti oluwa rẹ̀ gbé wà, titi ilẹ fi mọ́.
27 Oluwa rẹ̀ si dide li owurọ̀, o si ṣi ilẹ-
kun ile na, o si jade lati ba ọ̀na rẹ̀ lọ: si
kiyesi i obirin na, àle rẹ̀, ṣubu lulẹ li ẹnu-
ilẹkun ile na, ọwọ́ rẹ̀ si wà li ẹnu-ọ̀na na.
28 On si wi fun u pe, Dide, jẹ ki a ma
lọ; ṣugbọn kò sí ẹniti o dahùn: nigbana
li ọkọnrin na si gbé e lé ori kẹtẹkẹtẹ, ọkọn-
rin na si dide, o si lọ si ilu rẹ̀.
29 Nigbati o dé ile rẹ̀, on si mú ọbẹ, o
si mú àle rẹ̀ na, o si kun u ni-ike-ni-ike, o
si pín i si ọ̀na mejila, o si rán a lọ si gbo-
gbo àgbegbe Israeli.
30 O si ṣe, ti gbogbo awọn ẹniti o ri i
wipe, A kò ti ìhu irú ìwa bayi, bẽli a kò ti
iri i lati ọjọ́ ti awọn ọmọ Israeli ti gòke ti
ilẹ Egipti wá titi o fi di oni-oloni: ẹ rò o,
ẹ gbimọ̀, ki ẹ si sọrọ.

## ORI 20.

NIGBANA ni gbogbo awọn ọmọ Israeli
jade lọ, ijọ awọn enia si wọjọ pọ̀ bi
ọkọnrin kan, lati Dani lọ titi o fi dé Beeri-
ṣeba, pẹlu ilẹ Gileadi, si ọdọ OLUWA ni
Mispa.
2 Awọn olori gbogbo enia na, ani ti
gbogbo awọn ẹ̀ya Israeli, si pésẹ̀ larin ijọ
awọn enia Ọlọrun, ogún ọkẹ ọkọnrin ẹlẹsẹ̀
ti o kọ idà.
3 (Awọn ọmọ Benjamini si gbọ́ pe awọn
ọmọ Israeli gòke lọ si Mispa.) Awọn ọmọ

Digitized by Google

Israeli si wipe, Sọ fun wa, bawo ni ti ìwabuburu yi ti ri?
4 Ọkọnrin Lefi na, bale obirin na ti a pa, dahùn wipe, Mo wá si Gibea ti iṣe ti Benjamini, emi ati àle mi, lati wọ̀.
5 Awọn ọkọnrin Gibea si dide si mi, nwọn si yi ile na ká mọ́ mi li oru; nwọn si rò lati pa mi, nwọn si ba àle mi ṣe iṣekuṣe, o si kú.
6 Mo si mú àle mi, mo ke e wẹ́wẹ, mo si rán a lọ si gbogbo ilẹ-iní Israeli: nitoriti nwọn hù ìwakiwa ati ìwa wère ni Israeli.
7 Kiyesi i, ọmọ Israeli ni gbogbo nyin ṣe, ẹ mú èro ati ìmọran nyin wá.
8 Gbogbo awọn enia na si dide bi ọkọnrin kan, wipe, Kò sí ẹnikẹni ninu wa ti yio wọ̀ inu agọ́ rẹ̀ lọ, bẹ̃ni kò sí ẹnikẹni ti yio pada si ile rẹ̀.
9 Ṣugbọn nisisiyi eyi li ohun ti a o ṣe si Gibea; awa ṣẹ keké, awa o si gòke lọ sibẹ̀;
10 Awa o si mú ọkọnrin mẹwa ninu ọgọrun jalẹ ni gbogbo awọn ẹ̀ya Israeli, ati ọgọrun ninu ẹgbẹrun, ati ẹgbẹrun ninu ẹgbãrun, lati mú onjẹ fun awọn enia na wá, ki nwọn ki o le ṣe, nigbati nwọn ba dé Gibea ti Benjamini, gẹgẹ bi gbogbo ìwawère ti nwọn hù ni Israeli.
11 Bẹ̃ni gbogbo ọkọnrin Israeli jọ tì ilu na, nwọn fi ìmọ ṣọkan bi enia kan.
12 Awọn ẹ̀ya Israeli si rán ọkọnrin si gbogbo ẹ̀ya Benjamini, wipe, Ìwabuburu kili eyiti a hù lãrin nyin yi?
13 Njẹ nisisiyi ẹ mu awọn ọkọnrin na fun wa wá, awọn ọmọ Beliali, ti nwọn wà ni Gibea, ki awa ki o le pa wọn, ki awa ki o le mú ìwabuburu kuro ni Israeli. Ṣugbọn awọn ọmọ Benjamini kò fẹ́ fetisi ohùn awọn ọmọ Israeli awọn arakọnrin wọn.
14 Awọn ọmọ Benjamini si kó ara wọn jọ lati ilu wọnni wá si Gibea, lati jade lọ ibá awọn ọmọ Israeli jagun.
15 A si kà awọn ọmọ Benjamini li ọjọ́ na, lati ilu wọnni wá, nwọn jẹ́ ẹgbã mẹtala ọkọnrin ti nkọ idà, lẹhin awọn ara Gibea ti a kà, ẹdẹgbẹrin àṣayan ọkọnrin.
16 Ninu gbogbo awọn enia yi, a ri ẹdẹgbẹrin àṣayan ọkọnrin aṣòsi; olukuluku wọn le gbọ̀n kànakana ba fanran owu li aitase.
17 Ati awọn ọkọnrin Israeli, li àika Benjamini, si jẹ́ ogún ọkẹ enia ti o nkọ idà: gbogbo awọn wọnyi si jẹ́ ologun.
18 Awọn ọmọ Israeli si dide, nwọn si lọ si Beti-eli nwọn si bère lọdọ Ọlọrun, wipe, Tani ninu wa ti yio tètekọ gòke lọ ibá awọn ọmọ Benjamini jà? OLUWA si wipe, Juda ni yio tète gòke lọ.
19 Awọn ọmọ Israeli si dide li owurọ̀, nwọn si dótì Gibea.
20 Awọn ọkọnrin Israeli si jade lọ ibá Benjamini jà; awọn ọkọnrin Israeli si tẹ́gun dè wọn ni Gibea.
21 Awọn ọmọ Benjamini si ti Gibea jade wá, nwọn si pa ẹgba mọkanla enia ninu awọn ọmọ Israeli.
22 Awọn enia na, awọn ọkọnrin Israeli si gbà ara wọn niyanju, nwọn si tun tẹ́gun ni ibi ti nwọn kọ́ tẹ́gun si ni ijọ́ kini.
23 (Awọn ọmọ Israeli si gòke lọ, nwọn si sọkun niwaju OLUWA titi di aṣalẹ, nwọn si bère lọdọ OLUWA wipe, Ki emi ki o si tun lọ ibá awọn ọmọ Benjamini arakọnrin mi jà bi? OLUWA si wipe, Ẹ gòke tọ̀ ọ.)
24 Awọn ọmọ Israeli si sunmọ awọn ọmọ Benjamini ni ijọ́ keji.
25 Benjamini si jade si wọn lati Gibea wa ni ijọ́ keji, nwọn si pa ninu awọn ọmọ Israeli ẹgba mẹsan ọkọnrin; gbogbo awọn wọnyi li o nkọ́ idà.
26 Nigbana ni gbogbo awọn ọmọ Israeli, ati gbogbo awọn enia na gòke lọ, nwọn wá si Beti-eli, nwọn sọkun, nwọn si joko nibẹ̀ niwaju OLUWA, nwọn si gbàwẹ li ọjọ́ na titi di aṣalẹ; nwọn si ru ẹbọ sisun ati ẹbọ alafia niwaju OLUWA.
27 Awọn ọmọ Israeli si bère lọdọ OLUWA, (nitori ti apoti majẹmu Ọlọrun mbẹ nibẹ̀ li ọjọ́ wọnni.
28 Finehasi ọmọ Eleasari, ọmọ Aaroni si nduro niwaju rẹ̀ li ọjọ́ wọnni,) wipe, Ki emi ki o ha si tun gbogun jade si Benjamini arakọnrin mi bi? tabi ki emi ki o dẹkun? OLUWA si wipe, Ẹ gòke lọ; nitoripe li ọla emi o fi i lé ọ lọwọ.
29 Israeli si yàn awọn enia ti o ba yi Gibea ká.
30 Awọn ọmọ Israeli si gòke tọ̀ awọn ọmọ Benjamini lọ ni ijọ́ kẹta, nwọn si tẹ́gun si Gibea, gẹgẹ bi ìgba iṣaju.
31 Awọn ọmọ Benjamini si jade tọ̀ awọn enia na lọ, a si fà wọn kuro ni ilu; nwọn si bẹ̀rẹsi kọlù ninu awọn enia, nwọn npa, gẹgẹ bi ìgba iṣaju; li opópo wọnni ti o lọ si Beti-eli, ati ekeji si Gibea, ni pápa, nwọn pa ìwọn ọgbọ̀n ọkọnrin ninu Israeli.
32 Awọn ọmọ Benjamini si wipe, A lù wọn bolẹ niwaju wa, gẹgẹ bi ìgba iṣaju. Ṣugbọn awọn ọmọ Israeli wipe, Ẹ jẹ ki a sá, ki a si fà wọn kuro ni ilu si opópo.
33 Gbogbo awọn ọkọnrin Israeli si dide kuro ni ipò wọn, nwọn si tẹ́gun ni Baali-

Digitized by Google

tamari: awọn ti o wà ni ibuba ninu awọn enia Israeli si dide kuro ni ipo wọn, lati pápa Gibea wá.

34 Ẹgba marun ọkọnrin ti a ti yàn ninu gbogbo Israeli si lọ si Gibea, ìja na si le gidigidi: ṣugbọn nwọn kò si mọ̀ rí pe ibi sunmọ wọn.

35 OLUWA si kọlù Benjamini niwaju Israeli: awọn ọmọ Israeli si pa ẹgba mejila ọkọnrin o le ẹdẹgbẹfa li ọjọ́ na ninu awọn enia Benjamini: gbogbo awọn wọnyi li o kọ́ idà.

36 Bẽli awọn ọmọ Benjamini wa ri pe a ṣẹgun wọn: nitoriti awọn ọkọnrin Israeli bìṣẹhin fun awọn ara Benjamini nitoriti nwọn gbẹkẹle awọn ti o wà ni ibuba, ti nwọn yàn si eti Gibea.

37 Awọn ti o wà ni ibuba si yara, nwọn rọ́wọ̀ Gibea; awọn ti o wà ni ibuba si papọ̀, nwọn si fi oju idà kọlù gbogbo ilu na.

38 Njẹ àmi ti o wà lãrin awọn ọkọnrin Israeli, ati awọn ti o wà ni ibuba ni pe, ki nwọn jẹ ki ẽfi nla ki o rú soke lati ilu na wá.

39 Nigbati awọn ọkọnrin Israeli si pẹhinda ni ibi ìja na, Benjamini si bẹ̀rẹsi kọlù ninu awọn ọkọnrin Israeli, o si pa bi ọgbọ̀n enia: nitoriti nwọn wipe, Nitõtọ a lù wọn bolẹ niwaju wa, gẹgẹ bi ìja iṣaju.

40 Ṣugbọn nigbati awọsanma bẹ̀rẹsi rú soke lati ilu na wá pẹlu gọ́gọ ẽfi, awọn ara Benjamini wò ẹhin wọn, si kiyesi i, ẽfi gbogbo ilu na gòke lọ si ọrun.

41 Awọn ọkọnrin Israeli si yipada, awọn ọkọnrin Benjamini si damu: nitoriti nwọn ri pe ibi déba wọn.

42 Nitorina, nwọn pẹhinda niwaju awọn ọkọnrin Israeli si ọ̀na ijù; ṣugbọn ogun na lepa wọn kikan; ati awọn ti o ti ilu wọnni jade wá ni nwọn pa lãrin wọn.

43 Bẽni nwọn rọgba yi Benjamini ká, nwọn lepa wọn, nwọn tẹ̀ wọn mọlẹ ni ibi isimi, li ọkankan Gibea si ìha ila-õrùn.

44 Ẹgba mẹsan ọkọnrin li o si ṣubu ninu awọn enia Benjamini, gbogbo awọn wọnyi li akọni ọkọnrin.

45 Nwọn si yipada nwọn sálọ si ìha ijù sori okuta Rimmoni: nwọn si ṣà ẹgbẹdọgbọ̀n ọkọnrin ninu wọn li opópo; nwọn lepa wọn kikan dé Gidomu, nwọn si pa ẹgba ọkọnrin ninu wọn.

46 Bẽni gbogbo awọn ti o ṣubu ni ijọ́ na ninu awọn ara Benjamini jẹ́ ẹgba mejila ọkọnrin o le ẹgbẹrun ti o nkọ́ idà; gbogbo awọn wọnyi li akọni ọkọnrin.

47 Ṣugbọn ẹgbẹta ọkọnrin yipada, nwọn si sá si ìha ijù si ibi okuta Rimmoni, nwọn si joko sinu okuta Rimmoni li oṣù mẹrin.

48 Awọn ọkọnrin Israeli si pada tọ̀ awọn ọmọ Benjamini, nwọn si fi oju idà kọlù gbogbo ilu, ati ẹran, ati ohun gbogbo ti nwọn ní: gbogbo ilu ti nwọn ri ni nwọn fi iná kun pẹlu.

## ORI 21.

AWỌN ọkọnrin Israeli si ti bura ni Mispe, pe, Ẹnikan ninu wa ki yio fi ọmọbirin rẹ̀ fun Benjamini li aya.

2 Awọn enia na si wá si Beti-eli, nwọn si joko nibẹ̀ titi di aṣalẹ niwaju Ọlọrun nwọn si gbé ohùn wọn soke, nwọn si sọkun gidigidi.

3 Nwọn si wipe, OLUWA, Ọlọrun Israeli, ẽṣe ti o fi ri bayi ni Israeli, ti ẹ̀ya kan fi bùku li oni ninu awọn enia Israeli?

4 O si ṣe ni ijọ́ keji, awọn enia na dide ni kùtukutu owurọ̀, nwọn si mọ pẹpẹ kan nibẹ̀, nwọn si ru ẹbọ sisun, ati ẹbọ alafia.

5 Awọn ọmọ Israeli si wipe, Tali o wà ninu gbogbo awọn ẹ̀ya Israeli ti kò bá ijọ gòke tọ̀ OLUWA wá? Nitoripe nwọn ti bura nla niti ẹniti kò ba tọ̀ OLUWA wá ni Mispe, wipe, Pipa li a o pa a.

6 Awọn ọmọ Israeli si kãnu nitori Benjamini arakọnrin wọn, nwọn si wipe, A ke ẹ̀ya kan kuro ni Israeli li oni.

7 Awa o ha ti ṣe niti obirin fun awọn ti o kù, awa sá ti fi OLUWA bura pe, awa ki yio fi awọn ọmọbirin wa fun wọn li aya.

8 Nwọn si wipe, Ewo ni ninu awọn ẹ̀ya Israeli ti kò tọ̀ OLUWA wá ni Mispe? Si kiyesi i, kò sí ẹnikan ni ibudó ti o ti Jabeṣi-gileadi wá si ijọ.

9 Nitori nigbati a kà awọn enia na, si kiyesi i, kò sí ẹnikan nibẹ̀ ninu awọn ara Jabeṣi-gileadi.

10 Ijọ si rán ẹgbã mẹfa ọkọnrin ninu awọn akọni sibẹ̀, nwọn si fi aṣẹ fun wọn pe, Ẹ lọ ẹ si fi oju idà kọlù awọn ara Jabesi-gileadi, pẹlu awọn obirin ati awọn ọmọ wẹrẹ.

11 Eyiyi ni nkan ti ẹnyin o ṣe: gbogbo ọkọnrin, ati gbogbo obirin ti o ti mọ̀ ọkọnrin li ẹnyin o parun patapata.

12 Nwọn si ri irinwo wundia ninu awọn ara Jabeṣi-gileadi, ti kò ti imọ̀ ọkọnrin nipa ibadapọ̀: nwọn si mú wọn wá si ibudó ni Ṣilo, ti o wà ni ilẹ Kenaani.

13 Gbogbo ijọ si ranṣẹ lọ bá awọn ọmọ Benjamini ti o wà ninu okuta Rimmoni sọ̀rọ, nwọn si fi alafia lọ̀ wọn.

14 Benjamini si pada li akokò na: nwọn si fun wọn li obirin ti nwọn dasi ninu awọn

Digitized by Google

obirin Jabesi-gileadi: ṣugbọn sibẹ nwọn
kò si kari wọn.
15 Awọn enia na si kãnu nitori Ben-
jamini, nitoripe OLUWA ṣe afo ninu awọn
ẹya Israeli.
16 Nigbana li awọn àgba ijọ wipe, Kini
awa o ṣe niti obirin fun awọn iyokù, nito-
ripe a ti pa gbogbo awọn obirin run kuro
ni Benjamini?
17 Nwọn si wipe, Ilẹ-iní kan yio wà fun
awọn ti o ti sálà ni Benjamini, ki ẹya kan
ki o má ba parun kuro ni Israeli.
18 Ṣugbọn awa kò lè fi aya fun wọn ninu
awọn ọmọbirin wa: nitoriti awọn ọmọ Is-
raeli ti bura, wipe, Egún ni fun ẹniti o ba
fi aya fun Benjamini.
19 Nwọn si wipe, Kiyesi i, ajọ OLUWA
wà li ọdọdún ni Ṣilo ni iha ariwa Beti-eli,
ni iha ila-õrùn ti opópo ti o lọ soke lati
Beti-eli lọ titi dé Ṣekemu, ati ni iha gusù
ti Lebona.
20 Nwọn si fi aṣẹ fun awọn ọmọ Ben-
jamini wipe, Ẹ lọ ki ẹ si ba sinu ọgbà-
àjara;
21 Ki ẹ si wò, si kiyesi i, bi awọn ọ-
mọbirin Ṣilo ba jade wá lati jó ninu ijó
wọnni, nigbana ni ki ẹnyin ki o jade lati
inu ọgbà-àjara wá, ki olukuluku ọkọnrin
nyin ki o si mú aya rẹ̀ ninu awọn ọmọ-
birin Ṣilo, ki ẹnyin ki o si lọ si ilẹ Ben-
jamini.
22 Yio si ṣe, nigbati awọn baba wọn tabi
awọn arakọnrin wọn ba tọ̀ wa wá lati wijọ,
awa o si wi fun wọn pe, Ẹ ṣãnu wọn nitori
wa: nitoriti awa kò mú aya olukuluku
fun u li ogun na: bẹ̃ni ki iṣe ẹnyin li
o fi wọn fun wọn; nigbana ni ẹnyin iba
jẹbi.
23 Awọn ọmọ Benjamini si ṣe bẹ̃, nwọn
si mú aya, gẹgẹ bi iye wọn, ninu awọn ẹniti
njó, awọn ti nwọn múlọ; nwọn si lọ nwọn
pada si ilẹ-iní wọn, nwọn si kọ ilu wọnni,
nwọn si joko sinu wọn.
24 Nigbana li awọn ọmọ Israeli si lọ lati
ibẹ̀, olukuluku enia si ẹya tirẹ̀, ati si idile
tirẹ̀, nwon si jade lati ibẹ̀ lọ olukuluku enia
si ilẹ-iní tirẹ̀.
25 Li ọjọ́ wọnni ọba kan kò sí ni Israeli:
olukuluku nṣe eyiti o tọ́ li oju ara rẹ̀.

IWE TI

# RUTU.

## ORI 1.

O SI ṣe li ọjọ́ wọnni ti awọn onidajọ nṣe
olori, ìyan kan si mu ni ilẹ na. Ọkọn-
rin kan lati Beti-lehemu-juda si lọ ṣe atipo
ni ilẹ Moabu, on, ati obirin rẹ̀, ati awọn
ọmọ rẹ̀ ọkọnrin meji.
2 Orukọ ọkọnrin na a si ma jẹ́ Elimele-
ki, orukọ obirin rẹ̀ a si ma jẹ́ Naomi, orukọ
awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin mejeji a si ma jẹ́
Maloni ati Kilioni, awọn ara Efrata ti Beti-
lehemu-juda. Nwọn si wá si ilẹ Moabu,
nwọn si ngbé ibẹ̀.
3 Elimeleki ọkọ Naomi si kú; o si kù
on, ati awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin mejeji.
4 Nwọn si fẹ́ aya ninu awọn obirin Mo-
abu; orukọ ọkan a ma jẹ́ Orpa, orukọ ekeji
a si ma jẹ́ Rutu: nwọn si wà nibẹ̀ niwọn
ọdún mẹwa.
5 Awọn mejeji, Maloni ati Kilioni, si kú
pẹlu; obirin na li o si kù ninu awọn ọmọ
rẹ̀ ọkọnrin mejeji ati ọkọ rẹ̀.
6 Nigbana li o dide pẹlu awọn aya-ọmọ
rẹ̀, ki o le pada lati ilẹ Moabu wá: nito-
ripe o ti gbọ̀ ni ilẹ Moabu bi OLUWA ti bẹ̀
awọn enia rẹ̀ wò ni fifi onjẹ fun wọn.
7 O si jade kuro ni ibi ti o gbé ti wà,
ati awọn aya-ọmọ rẹ̀ mejeji pẹlu rẹ̀; nwọn
si mu ọna pọn lati pada wá si ilẹ Juda.
8 Naomi si wi fun awọn aya-ọmọ rẹ̀
mejeji pe, Ẹ lọ, ki olukuluku pada lọ si ile
iya rẹ̀: ki OLUWA ki o ṣe rere fun nyin,
gẹgẹ bi ẹnyin ti ṣe fun awọn okú, ati
fun mi.
9 Ki OLUWA ki o fi fun nyin ki ẹnyin le
ri isimi, olukuluku nyin ni ile ọkọ rẹ̀.
Nigbana li o fi ẹnu kò wọn lẹnu; nwọn si
gbé ohùn wọn soke nwọn si sọkun.

Digitized by Google

10 Nwọn si wi fun u pe, Nitõtọ awa o
bá ọ pada lọ sọdọ awọn enia rẹ.
11 Naomi si wipe, Ẹnyin ọmọbirin mi ẹ
pada: ẽṣe ti ẹnyin o fi bá mi lọ? mo ha tun
ní ọmọkọnrin ni inu mi, ti nwọn iba fi ṣe
ọkọ nyin?
12 Ẹ pada, ẹnyin ọmọbirin mi, ẹ ma lọ;
nitori emi di arugbo jù ati ní ọkọ. Bi emi
wipe, Emi ní ireti, bi emi tilẹ ní ọkọ li alẹ
yi, ti emi si bi ọmọkọnrin;
13 Ẹnyin ha le duro dè wọn titi nwọn o
fi dàgba? Ẹnyin o le duro dè wọn li ainí
ọkọ? ndao, ẹnyin ọmọbirin mi; nitoripe
inu mi bàjẹ́ gidigidi nitori nyin, ti ọwọ́
OLUWA fi jade si mi.
14 Nwọn si gbé ohùn wọn soke, nwọn si
tun sọkun: Orpa si fi ẹnu kò iya-ọkọ rẹ̀
lẹnu; ṣugbọn Rutu fàmọ́ ọ.
15 On si wipe, Kiyesi i, orogun rẹ pada
sọdọ awọn enia rẹ̀, ati sọdọ oriṣa rẹ̀: iwọ
pada tẹlé orogun rẹ.
16 Rutu si wipe, Máṣe rọ̀ mi lati fi ọ silẹ,
tabi lati pada kuro lẹhin rẹ: nitori ibiti
iwọ ba lọ, li emi o lọ; ibi ti iwọ ba si wọ̀,
li emi o wọ̀: awọn enia rẹ ni yio ma ṣe
enia mi, Ọlọrun rẹ ni yio si ma ṣe Ọlọrun
mi:
17 Ibiti iwọ ba kú li emi o kú si, nibẹ̀
li a o si sin mi: ki OLUWA ki o ṣe bẹ̃ si mi,
ati jù bẹ̃ lọ pẹlu, bi ohun kan bikoṣe ikú
ba yà iwọ ati emi.
18 Nigbati on ri pe o ti pinnu rẹ̀ tán
lati bá on lọ, nigbana li o dẹkun ọ̀rọ ibá a
sọ.
19 Bẽni awọn mejeji lọ titi nwọn fi dé
Beti-lehemu. O si ṣe, ti nwọn dé Beti-
lehemu, gbogbo ilu si dide nitori wọn,
nwọn si wipe, Naomi li eyi?
20 On si wi fun wọn pe, Ẹ má pè mi ni
Naomi mọ́, ẹ mã pè mi ni Mara: nitoriti
Olodumare hùwa kikorò si mi gidigidi.
21 Mo jade lọ ni kikún, OLUWA si tun
mú mi pada bọ̀wá ile li ofo: ẽhaṣe ti ẹnyin
fi npè mi ni Naomi, nigbati OLUWA ti
jẹriti mi, Olodumare si ti pọn mi loju?
22 Bẽni Naomi padawá, ati Rutu ara
Moabu, aya-ọmọ rẹ̀ pẹlu rẹ̀, ẹniti o ti ilẹ
Moabu wá; nwọn si wá si Beti-lehemu ni
ìbẹrẹ ikore ọkà-barle.

## ORI 2.

NAOMI si ní ibatan ọkọ rẹ̀ kan, ọlọrọ̀
pupọ̀, ni idile Elimeleki; orukọ rẹ̀ a
si ma jẹ́ Boasi.
2 Rutu ara Moabu si wi fun Naomi pe,
Jẹ ki emi lọ si oko nisisiyi, ki emi si ma
peṣẹ́-ọkà lẹhin ẹniti emi o ri ore-ọfẹ li oju
rẹ̀. On si wipe, Lọ, ọmọbirin mi.
3 On si lọ, o si dé oko, o si peṣẹ́-ọkà
lẹhin awọn olukore: o si wa jẹ pe apa oko
ti o bọ si jẹ́ ti Boasi, ti iṣe ibatan Eli-
meleki.
4 Si kiyesi i, Boasi ti Beti-lehemu wá, o
si wi fun awọn olukore pe, Ki OLUWA ki o
wà pẹlu nyin. Nwọn si da a lohùn pe, Ki
OLUWA ki o bukún u fun o.
5 Nigbana ni Boasi wi fun iranṣẹ rẹ̀ ti a
fi ṣe olori awọn olukore pe, Ọmọbirin tani
yi?
6 Iranṣẹ na ti a fi ṣe olori awọn olukore
dahùn, o si wipe, Ọmọbirin ara Moabu ni,
ti o bá Naomi ti ilẹ Moabu wa.
7 O si wipe, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki emi ma
peṣẹ-ọkà, ki emi si ma ṣà lẹhin awọn olu-
kore ninu ití: bẽli o wá, o si duro ani lati
owurọ̀ titi di isisiyi, bikoṣe ìgba diẹ ti o
simi ninu ile.
8 Nigbana ni Boasi wi fun Rutu pe, Iwọ
kò gbọ́, ọmọbirin mi? Máṣe lọ peṣẹ́-ọkà
li oko miran, bẽni ki iwọ ki o máṣe re ihin
kọja, ṣugbọn ki o faramọ́ awọn ọmọbirin
mi nihin.
9 Jẹ ki oju rẹ ki o wà ninu oko ti nwọn
nkore rẹ̀, ki iwọ ki o si ma tẹle wọn: emi
kò ha ti kilọ fun awọn ọmọkọnrin ki nwọn
ki o máṣe tọ́ ọ? ati nigbati ongbẹ ba ngbẹ
ọ, lọ si ibi àmu, ki o si mu ninu eyiti awọn
ọmọkọnrin ti pọn.
10 Nigbana ni o wolẹ, o si tẹ̀ ara rẹ̀ ba
silẹ, o si wi fun u pe, Ẽṣe ti mo ri ore ọfẹ
li oju rẹ, ti iwọ o fi kiyesi mi, bẽni alejo li
emi?
11 Boasi si da a lohùn o si wi fun u pe,
Gbogbo ohun ti iwọ ṣe fun iya-ọkọ rẹ lati
ìgba ikú ọkọ rẹ, li a ti rò fun mi patapata:
ati bi iwọ ti fi baba ati iya rẹ, ati ilẹ ibi
rẹ silẹ, ti o si wá sọdọ awọn enia ti iwọ kò
mọ̀ rí.
12 Ki OLUWA ki o san ẹsan iṣẹ rẹ, ẹsan
kikún ni ki a san fun ọ lati ọwọ́ OLUWA
Ọlọrun Israeli wá, labẹ apa-iyẹ́ ẹniti iwọ
wá gbẹkẹle.
13 Nigbana li o wipe, Oluwa mi, jẹ ki
emi ri ore-ọfẹ li oju rẹ; iwọ sá tù mi ninu,
iwọ sá si ti sọ̀rọ rere fun ọmọ-ọdọ rẹ obirin,
bi o tilẹ ṣe pe emi kò ri bi ọkan ninu awọn
ọmọ-ọdọ rẹ obirin.
14 Li akokò onjẹ, Boasi si wi fun u pe,
Iwọ sunmọ ihin, ki o si jẹ ninu onjẹ, ki o
si fi òkele rẹ bọ̀ inu ọtikikan. On si joko
lẹba ọdọ awọn olukore: o si nawọ́ ọkà di-
din si i, o si je. o si yó, o si kùsilẹ.

Digitized by Google

15 Nigbati o si dide lati peṣẹ́-ọkà, Boasi si paṣẹ fun awọn ọmọkọnrin rẹ̀, wipe, Ẹ jẹ ki o peṣẹ́-ọkà ani ninu awọn ití, ẹ má si ṣe bá a wi.

16 Ki ẹ si yọ diẹ ninu ití fun u, ki ẹ si fi i silẹ, ki ẹ si jẹ ki o ṣà a, ẹ má si ṣe bá a wi.

17 Bẽli o peṣẹ́-ọkà li oko titi o fi di aṣalẹ; o si gún eyiti o kójọ, o si to bi òṣuwọn efa ọkà-barle kan.

18 O si gbé e, o si lọ si ilu: iya-ọkọ rẹ̀ si ri ẽṣẹ́ ti o pa: on si mú jade ninu eyiti o kù lẹhin ti o yó, o si fi fun u.

19 Iya-ọkọ rẹ̀ si wi fun u pe, Nibo ni iwọ gbé peṣẹ́ li oni? nibo ni iwọ si ṣiṣẹ? ibukún ni fun ẹniti o fiyesi ọ. O si sọ ọdọ ẹniti on ṣiṣẹ fun iya-ọkọ rẹ̀, o si wipe, Boasi li orukọ ọkọnrin ti mo ṣiṣẹ lọdọ rẹ̀ li oni.

20 Naomi si wi fun aya-ọmọ rẹ̀ pe, Ibukún ni fun u lati ọdọ OLUWA wá, ẹniti kò dẹkun ore rẹ̀ lati ṣe fun awọn alãye, ati fun awọn okú. Naomi si wi fun u pe, Ọkọnrin na sunmọ wa, ibatan ti o sunmọ wa ni.

21 Rutu obirin Moabu na si wipe, O wi fun mi pẹlu pe, Ki iwọ ki o faramọ́ awọn ọdọmọkọnrin mi, titi nwọn o fi pari gbogbo ikore mi.

22 Naomi si wi fun Rutu aya-ọmọ rẹ̀ pe, O dara, ọmọbirin mi, ki iwọ ki o ma bá awọn ọmọbirin ọdọ rẹ̀ jade, ki nwọn ki o má ṣe bá ọ pade li oko miran.

23 Bẽli o faramọ́ awọn ọmọbirin ọdọ Boasi lati ma peṣẹ́-ọkà titi ipari ikore ọkà-barle ati ti alikama; o si wà lọdọ iya-ọkọ rẹ̀.

## ORI 3.

NAOMI iya-ọkọ rẹ̀ si wi fun u pe, Ọmọbirin mi, emi ki yio ha wá ibi isimi fun ọ, ki o le dara fun ọ?

2 Njẹ nisisiyi ibatan wa ki Boasi iṣe, ọmọbirin ọdọ ẹniti iwọ ti mbá gbé? Kiyesi i, o nfẹ ọkà-barle li alẹ yi ni ilẹ-ipakà rẹ̀.

3 Nitorina wẹ̀, ki o si para, ki o si wọ̀ aṣọ rẹ, ki o si sọkalẹ lọ si ilẹ-ipakà: ṣugbọn má ṣe jẹ ki ọkọnrin na ki o ri ọ titi on o fi jẹ ti on o si mu tán.

4 Yio si ṣe, nigbati o ba dubulẹ, ki iwọ ki o kiyesi ibi ti on o sùn si, ki iwọ ki o wọle, ki o si ṣí aṣọ ẹsẹ̀ rẹ̀, ki o si dubulẹ; on o si sọ ohun ti iwọ o ṣe fun ọ.

5 O si wi fun u pe, Gbogbo eyiti iwọ wi fun mi li emi o ṣe.

6 O si sọkalẹ lọ si ilẹ-ipakà na, o si ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti iya-ọkọ rẹ̀ palaṣẹ fun u.

7 Nigbati Boasi si jẹ ti o si mu tán, ti inu rẹ̀ si dùn, o lọ dubulẹ ni ikangun ikójọ ọkà: on si wá jẹjẹ, o si ṣí aṣọ ẹsẹ̀ rẹ̀, o si dubulẹ.

8 O si ṣe lãrin ọganjọ ẹ̀ru bà ọkọnrin na, o si yi ara pada: si kiyesi i, obirin kan dubulẹ lẹba ẹsẹ̀ rẹ̀.

9 O si wipe, Iwọ tani nì? On si dahùn wipe, Emi Rutu ọmọbirin ọdọ rẹ ni: nitorina nà eti-aṣọ rẹ bò ọmọbirin ọdọ rẹ; nitori iwọ ni ibatan ti o sunmọ wa.

10 On si wipe, Alabukun ni iwọ lati ọdọ OLUWA wá, ọmọbirin mi: nitoriti iwọ ṣe ore ikẹhin yi jù ti iṣaju lọ, niwọnbi iwọ kò ti tẹle awọn ọmọkọnrin lẹhin, iba ṣe talakà tabi ọlọrọ̀.

11 Njẹ nisisiyi, ọmọbirin mi máṣe bẹ̀ru; gbogbo eyiti iwọ wi li emi o ṣe fun ọ: nitori gbogbo agbajọ awọn enia mi li o mọ̀ pe obirin rere ni iwọ iṣe.

12 Njẹ nisisiyi ibatan ti o sunmọ nyin li emi iṣe nitõtọ: ṣugbọn ibatan kan wà ti o sunmọ nyin jù mi lọ.

13 Duro li oru yi, yio si ṣe li owurọ̀, bi on o ba ṣe iṣe ibatan si ọ, gẹgẹ; jẹ ki o ṣe iṣe ibatan: ṣugbọn bi kò ba fẹ́ ṣe iṣe ibatan si ọ, nigbana ni emi o ṣe iṣe ibatan si ọ, bi OLUWA ti wà: dubulẹ titi di owurọ̀.

14 On si dubulẹ lẹba ẹsẹ̀ rẹ̀ titi di owurọ̀: o si dide ki ẹnikan ki o to mọ̀ ẹnikeji. On si wipe, Má ṣe jẹ ki a mọ̀ pe obirin kan wá si ilẹ-ipakà.

15 O si wipe, Mú aṣọ-ileke ti mbẹ lara rẹ wá, ki o si dì i mú: nigbati o si dì i mú, o wọ̀n òṣuwọn ọkà-barle mẹfa, o si gbé e rù u: on si wọ̀ ilu lọ.

16 Nigbati o si dé ọdọ iya-ọkọ rẹ̀, on wipe, Iwọ tani nì ọmọbirin mi? O si wi gbogbo eyiti ọkọnrin na ṣe fun on fun u.

17 O si wipe, Òṣuwọn ọkà-barle mẹfa wọnyi li o fi fun mi; nitori o wi fun mi pe, Máṣe ṣanwọ tọ̀ iya-ọkọ rẹ lọ.

18 Nigbana li on wipe, Joko jẹ, ọmọbirin mi, titi iwọ o fi mọ̀ bi ọ̀ran na yio ti jasi: nitoripe ọkọnrin na ki yio simi, titi yio fi pari ọ̀ran na li oni.

## ORI 4.

NIGBANA ni Boasi lọ si ẹnu-bode, o si joko nibẹ̀: si kiyesi i, ibatan na ẹniti Boasi sọrọ rẹ̀ nkọja; o si pe, Iwọ alamọrin! yà, ki o si joko nihin. O si yà, o si joko.

2 O si mú ọkọnrin mẹwa ninu awọn àgba ilu, o si wipe, Ẹ joko nihin. Nwọn si joko.

3 O si wi fun ibatan na pe, Naomi, ẹniti

Digitized by Google

o ti ilẹ Moabu pada wa, o ntà ilẹ kan, ti iṣe ti Elimeleki arakọnrin wa:

4 Mo si rò lati ṣí ọ leti rẹ̀, wipe, Rà a niwaju awọn ti o joko nihin, ati niwaju awọn àlagba awọn enia mi. Bi iwọ o ba rà a silẹ rà a silẹ: ṣugbọn bi iwọ ki yio ba rà a silẹ, njẹ wi fun mi, ki emi ki o le mọ̀: nitoriti kò sí ẹnikan lati rà a silẹ lẹhin rẹ; emi li o si tẹle ọ. On si wipe, Emi o rà a silẹ.

5 Nigbana ni Boasi wipe, Li ọjọ́ ti iwọ ba rà ilẹ na li ọwọ́ Naomi, iwọ kò le ṣe àirà a li ọwọ́ Rutu ara Moabu pẹlu, aya ẹniti o kú, lati gbé orukọ okú dide lori ilẹ-iní rẹ̀.

6 Ibatan na si wipe, Emi kò le rà a silẹ fun ara mi, ki emi má ba bà ilẹ-iní mi jẹ́: iwọ rà eyiti emi iba ràsilẹ; nitori emi kò le rà a.

7 Iṣe wọn nigbãni ni Israeli niti ìrasilẹ ati niti ìparọ si li eyi, lati fi idí ohun gbogbo mulẹ, ẹnikini a bọ́ bàta rẹ̀, a si fi i fun ẹnikeji rẹ̀: ẹrí li eyi ni Israeli,

8 Bẽni ibatan na wi fun Boasi pe, Rà a fun ara rẹ. O si bọ́ bàta rẹ̀.

9 Boasi si wi fun awọn àgbagba, ati fun gbogbo awọn enia pe, Ẹnyin li ẹlẹri li oni, pe, mo rà gbogbo nkan ti iṣe ti Elimeleki, ati gbogbo nkan ti iṣe ti Kilioni, ati ti Maloni, li ọwọ́ Naomi.

10 Pẹlupẹlu Rutu ara Moabu, aya Maloni ni mo rà li aya mi, lati gbé orukọ okú dide lori ilẹ-iní rẹ̀, ki orukọ okú ki o má ba run ninu awọn arakọnrin rẹ̀, ati li ẹnubode ilu rẹ̀: ẹnyin li ẹlẹri li oni.

11 Gbogbo awọn enia ti o wà li ẹnu-bode, ati awọn àgbagba, si wipe, Awa ṣe ẹlẹri. Ki OLUWA ki o ṣe obirin na ti o wọ̀ ile rẹ bi Rakeli ati bi Lea, awọn meji ti o kọ ile Israeli: ki iwọ ki o si jasi ọlọlá ni Efrata, ki o si jasi olokikí ni Beti-lehemu.

12 Ki ile rẹ ki o si dabi ile Peresi, ẹniti Tamari bi fun Juda, nipa irú-ọmọ ti OLUWA yio fun ọ lati ọdọ ọmọbirin yi.

13 Boasi si mú Rutu, on si di aya rẹ̀, nigbati o si wọle tọ̀ ọ, OLUWA si mu ki o lóyun, o si bi ọmọkọnrin kan.

14 Awọn obirin si wi fun Naomi pe, Olubukun li OLUWA, ti kò fi ọ silẹ li ainí ibatan li oni, ki o si jẹ́ olokikí ni Israeli.

15 On o si jẹ́ olumupada ẹmi rẹ, ati olutọju ogbó rẹ: nitori aya-ọmọ rẹ, ẹniti o fẹ́ ọ, ti o san fun ọ jù ọmọkọnrin meje lọ, li o bi i.

16 Naomi si gbé ọmọ na, o si tẹ́ ẹ si owokan-àiya rẹ̀, o si di alagbatọ́ rẹ̀.

17 Awọn obirin aladugbo rẹ̀ si sọ ọ li orukọ, wipe, A bi ọmọkọnrin kan fun Naomi; nwọn si pè orukọ rẹ̀ ni Obedi: on ni baba Jesse, baba Dafidi.

18 Wọnyi ni iran Peresi: Peresi bi Hesroni;

19 Hesroni si bi Ramu, Ramu si bi Amminadabu;

20 Amminadabu si bi Naṣoni, Naṣoni si bi Salmoni;

21 Salmoni si bi Boasi, Boasi si bi Obedi;

22 Obedi si bi Jesse, Jesse si bi Dafidi.

---

IWE KINI TI

# SAMUELI.

## ORI 1.

NIGBANA ọkọnrin kan wà, ara Ramataim-sofimu, li oke Efraimu, orukọ rẹ̀ ama jẹ Elkana, ọmọ Jerohamu, ọmọ Elihu, ọmọ Tohu, ọmọ Sufu, ara Efrata.

2 O si ni aya meji; orukọ ekini ama jẹ Hanna, orukọ ekeji a si ma jẹ Peninna: Peninna si bimọ, ṣugbọn Hanna kò bi.

3 Ọkọnrin yi a ma ti ilu rẹ̀ lọ lọdọdun lati sìn ati lati ṣe irubọ si Oluwa awọn ọmọ-ogun ni Ṣilo. Ọmọ Eli mejeji Hofni ati Finehasi alufa Oluwa, si wà nibẹ.

4 Nigbati o si di akoko ti Elkana ṣe irubọ o fi ipin fun Peninna aya rẹ̀, ati fun gbogbo ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, ati fun awọn ọmọ rẹ̀ obirin.

5 Ṣugbọn Hanna li on fi ipin ẹni meji fun; nitori ti o fẹ Hanna: ṣugbọn Oluwa ti se e ni inu.

Digitized by Google

6 Orogún rẹ̀ pẹlu a si ma tọ́ ọ gidigidi
lati mu u binu, nitoriti Oluwa ti se e ni
inu.
7 Bi on iti ma ṣe bẽ lọdọdun, nigbati
Hanna ba goke lọ si ile Oluwa, bẹni Penin-
na ima bà a ni inu jẹ; nitorina ama sọkun,
kò si jẹun.
8 Nigbana ni Elkana ọkọ rẹ̀ si sọ fun u
pe, Hanna, ẽṣe ti iwọ nsọkun? ẽṣe ti iwọ
kò si jẹun? ẽsi ti ṣe ti inu rẹ fi bajẹ? emi
ko ha sàn fun ọ ju ọmọ mẹwa lọ bi?
9 Bẽni Hanna si dide lẹhin igbati wọn
jẹ, ti nwọn si mu tan ni Ṣilo. Eli alufa si
joko lori apoti li ẹba opó tempili Oluwa.
10 On si wà ninu ibinujẹ ọkàn, o si mbẹ
Oluwa, o si sọkun gidigidi.
11 On si jẹ́'jẹ, o si wipe, Oluwa awọn
ọmọ-ogun, bi iwọ nitõtọ ba bojuwo ipọnju
iranṣẹbirin rẹ, ti o si ranti mi, ti iwọ kò si
gbagbe iranṣẹbirin rẹ, ṣugbọn bi iwọ ba fi
ọmọkọnrin kan fun iranṣẹbirin rẹ, nigbana
li emi o fi i fun Oluwa ni gbogbo ọjọ aiye
rẹ̀, abẹ kì yio si kàn a lori.
12 O si ṣe bi o ti mbẹbẹ sibẹ niwaju
Oluwa, bẽni Eli kiyesi ẹnu rẹ̀.
13 Njẹ Hanna, on nsọ̀rọ li ọkàn rẹ̀; ki-
ki etè rẹ̀ li o nmì, ṣugbọn a kò gbọ́ ohùn
rẹ̀; nitorina ni Eli fi rò pe, o mu ọti-waini
yó.
14 Eli si wi fun u pe, Iwọ o ti mu ọti-
waini pẹ to? mu ọti-waini rẹ kuro lọdọ rẹ.
15 Hanna si dahun wipe, Bẽkọ, oluwa
mi, emi li obirin onirọ̀binujẹ ọkàn: emi
kò mu oti-waini tabi ọti lile, ṣugbọn ọkàn
mi li emi ntú jade niwaju Oluwa.
16 Má ṣe ka iranṣẹbirin rẹ si ọmọbirin
Beliali: nitoripe ninu ọ̀pọlọpọ irò ati ibinu-
jẹ inu mi ni mo ti nsọ disisiyi.
17 Nigbana ni Eli dahun o si wipẹ, Ma
lọ li alafia: ki Ọlọrun Israeli ki o fi idahun
ibere ti iwọ bere lọdọ rẹ̀ fun ọ.
18 On si wipe, Ki iranṣẹbirin rẹ ki o ri
ore-ọfẹ loju rẹ. Bẽli obirin na ba tirẹ̀ lọ,
o si jẹun, kò si fà oju ro mọ.
19 Nwọn si dide ni kutukutu owurọ̀,
nwọn wolẹ sìn niwaju Oluwa, nwọn pada
wá si ile wọn si Rama: Elkana si mọ aya
rẹ̀; Oluwa si ranti rẹ̀.
20 Nitorina, o si ṣe, nigbati ọjọ rẹ̀ pe
lẹhin igbati Hanna loyun, o si bi ọmọkọn-
rin kan, o si pe orukọ rẹ̀ ni Samueli, pe,
Nitoriti mo bere rẹ̀ lọwọ Oluwa.
21 Ọkọnrin na Elkana, ati gbogbo awọn
ara ile rẹ̀, goke lọ lati rubọ ọdun si Oluwa,
ati lati san ileri ifẹ rẹ̀.
22 Ṣugbọn Hanna kò goke lọ; nitori ti
o wi fun ọkọ rẹ̀ pe, o di igbati mo ba gba
ọmu lẹnu ọmọ na, nigbana li emi o mu u
lọ, ki on ki o le fi ara han niwaju Oluwa,
ki o si ma gbe ibẹ titi lai.
23 Elkana ọkọ rẹ̀ si wi fun u pe, Ṣe eyi
ti o tọ li oju rẹ; duro titi iwọ o fi gba ọmu
li ẹnu rẹ̀; ṣugbọn ki Oluwa ki o sa mu ọ̀rọ
rẹ̀ ṣẹ. Bẽli obirin na si joko, o si fi ọmu
fun ọmọ rẹ̀ titì o fi gbà a lẹnu rẹ̀.
24 Nigbati o si gba ọmu li ẹnu rẹ̀, o si
mu u goke lọ pẹlu ara rẹ̀, pẹlu ẹgbọrọ malu
mẹta, ati iyẹfun efa kan, ati igo ọti-waini
kan, o si mu u wá si ile Oluwa ni Ṣilo:
ọmọ na si wà li ọmọde.
25 Nwọn pa ẹgbọrọ malu, nwọn si mu
ọmọ na tọ̀ Eli wá.
26 Hanna si wipe, oluwa mi, bi ọkàn rẹ̀
ti wà lãye, oluwa mi, emi li obirin na ti o
duro li ẹba ọdọ rẹ nihin ti ntọrọ lọdọ
Oluwa.
27 Ọmọ yi ni mo ntọrọ; Oluwa si fi
idahun ibere ti mo bere lọdọ rẹ̀ fun mi:
28 Nitorina pẹlu emi fi i fun Oluwa; ni
gbogbo ọjọ aiye rẹ̀: nitoriti mo ti bere rẹ̀
fun Oluwa. Nwọn si wolẹ-sin Oluwa nibẹ.

## ORI 2.

HANNA si gbadura pe, Ọkàn mi yọ̀ si
Oluwa, iwo mi li a si gbe soke si
Oluwa: ẹnu mi si gboro lori awọn ọta mi;
nitoriti emi yọ̀ ni igbala rẹ.
2 Kò si ẹniti o mọ́ bi Oluwa: kò si
ẹlomiran bọyẹ̀ ni iwọ; bẽni kò si apata bi
Ọlọrun wa.
3 Màṣe halẹ; má jẹ ki igberaga ki o ti
ẹnu nyin jade: nitoripe Ọlọrun olùmọ̀ ni
Oluwa, lati ọdọ rẹ̀ wá li ati iwọ̀n ìwa.
4 Ọrun awọn alagbara ti ṣẹ, awọn ti o
sebú li a fi agbara dì li amure.
5 Awọn ti o yo fun onjẹ ti fi ara wọn ṣe
alagbaṣe: awọn ti ebi npa kò si ṣe alaini:
tobẹ̃ ti àgan fi bi meje: ẹniti o bimọ pipọ
si di alailagbara.
6 Oluwa pa o si sọ di ayè: o mu sọkalẹ
lọ si iboji, o si gbe soke.
7 Oluwa sọ di talaka, o si sọ di ọlọrọ̀: o
rẹ̀ silẹ, o si gbe soke.
8 O gbe talaka soke lati inu erupẹ wá, o
gbe alagbe soke lati ori ãtàn wá, lati ko
wọn jọ pẹlu awọn ọmọ-alade, lati mu wọn
jogun itẹ ogọ: nitori pe ọwọ̀n aiye ti Oluwa
ni, o si ti gbe aiye ka ori wọn.
9 Yio pa ẹsẹ awọn enia mimọ́ rẹ̀ mọ,
awọn enia buburu ni yio dakẹ li okunkun;
nipa agbara kò si ọkọnrin ti yio bori.
10 Ao fọ́ awọn ọta Oluwa tutu; lati



Digitized by Google

ọrun wá ni yio san ără si wọn: Oluwa yio ṣe idajọ opin aiye; yio fi agbara fun ọba rẹ̀, yio si gbe iwo ẹni-amì-ororo rẹ̀ soke.

11 Elkana si lọ si Rama si ile rẹ̀. Ọmọ na si nṣe iranṣẹ fun Oluwa niwaju Eli alufa.

12 Awọn ọmọ Eli si jẹ ọmọ Beliali; nwọn kò mọ̀ Oluwa.

13 Iṣe awọn alufa pẹlu awọn enia ni, nigbati ẹnikan ba ṣe irubọ, iranṣẹ alufa a de, nigbati ẹran na nho lori iná, ti on ti ọpa-ẹran oniga mẹta li owọ́ rẹ̀.

14 On a si fi gun inu apẹ, tabi kẹtili tabi òdu, tabi ikoko, gbogbo eyi ti ọpa-ẹran oniga na ba mu wá oke, alufa a mu u fun ara rẹ̀. Bẽni nwọn nṣe si gbogbo Israeli ti o wá si ibẹ̀ ni Ṣilo.

15 Pẹlu ki nwọn ki o to sun ọra na iranṣẹ alufa a de, a si wi fun ọkọnrin ti o ṣe irubọ pe, Fi ẹran fun mi lati sun fun alufa; nitoriti kì yio gba ẹran sisè lọwọ rẹ, bikoṣe tutù.

16 Ọkọnrin na si wi fun u pe, Jẹ ki wọn sun ọra na nisisiyi, ki o si mu iyekiye ti ọkàn rẹ ba fẹ; nigbana li o da a lohun pe, Bẽkọ, ṣugbọn ki iwọ ki o fi i fun mi nisisiyi: bikoṣe bẽ, emi o fi agbara gbà a.

17 Ẹṣẹ awọn ọdọmọkọnrin na si tobi gidigidi niwaju Oluwa: nitoriti enia korira ẹbọ Oluwa.

18 Ṣugbọn Samueli nṣe iranṣẹ niwaju Oluwa, o ṣe ọmọde, ti a wọ̀ ni efodi ọgbọ.

19 Pẹlupẹlu iya rẹ̀ da aṣọ ileke penpe fun u, a ma mu fun u wá lọdọdun, nigbati o ba bá ọkọ rẹ̀ goke wá lati ṣe irubọ ọdun.

20 Eli sure fun Elkana ati aya rẹ̀ pe, ki Oluwa ki o ti ara obirin yi fun ọ ni iru-ọmọ nipa ibere na ti o bere lọdọ Oluwa. Nwọn si lọ si ile wọn.

21 Oluwa si boju wo Hanna, o si loyun, o bi ọmọkọnrin mẹta ati ọmọbirin meji. Samueli ọmọ na si ndagbà niwaju Oluwa.

22 Eli si di arugbo gidigidi, o si gbọ́ gbogbo eyi ti awọn ọmọ rẹ̀ ṣe si gbogbo Israeli; ati bi nwọn ti ima ba awọn obirin sùn, ti nwọn ma pejọ li ẹnu ọ̀na agọ ajọ.

23 O si wi fun wọn pe, Etiri ti emi fi ngbọ́ iru nkan bẽ si nyin? nitoriti emi ngbọ́ iṣe buburu nyin lati ọdọ gbogbo enia yi wá.

24 Bẽkọ, ẹnyin ọmọ mi, nitori ki iṣe ihinrere li emi gbọ́: ẹnyin mu enia Ọlọrun dẹṣẹ̀.

25 Bi ẹnikan ba ṣẹ̀ si ẹnikeji, onidajọ yio ṣe idajọ rẹ̀: ṣugbọn bi ẹnikan ba ṣẹ̀ sí Oluwa, tani yio bẹ̀bẹ fun u? Nwọn kò si fi eti si ohùn baba wọn, nitoriti Oluwa nfẹ pa wọn.

26 Ọmọ na Samueli ndagba, o si ri ojurere lọdọ Oluwa, ati enia pẹlu.

27 Ẹni Ọlọrun kan tọ Eli wá, o si wi fun u pe, Bayi li Oluwa wi, Gbangba ki emi fi ara hàn ile baba rẹ, nigbati nwọn mbẹ ni Egipti ninu ile Farao?

28 Emi ko si yàn a kuro larin gbogbo ẹya Israeli lati jẹ alufa mi, lati rubọ lori pẹpẹ mi, lati fi turari jona, lati wọ efodi niwaju mi, emi si fi gbogbo ẹbọ ti ọmọ Israeli ima fi iná sun fun idile baba rẹ?

29 Eṣe ti ẹnyin fi tapa si ẹbọ ati ọrẹ mi, ti mo pa li aṣẹ ni ibujoko mi: iwọ si bu ọla fun awọn ọmọ rẹ jù mi lọ, ti ẹ si fi gbogbo ăyo ẹbọ Israeli awọn enia mi mu ara nyin sanra?

30 Nitorina Oluwa Ọlọrun Israeli wipe, Emi ti wi nitotọ pe, ile rẹ ati ile baba rẹ, yio ma rin niwaju mi titi: ṣugbọn nisisiyi Oluwa wipe, ki a má ri i; awọn ti o bu ọla fun mi li emi o bu ọla fun, ati awọn ti kò kà mi si li a o si ṣe alaikasi.

31 Kiye si i, ọjọ wọnni mbọ̀, ti emi o ke iru rẹ kurò, ati iru baba rẹ, kì yio si arugbo kan ninu ile rẹ.

32 Iwọ o ri wahala ti Agọ, ninu gbogbo ọlà ti Ọlọrun yio fi fun Israeli: kì yio si si arugbo kan ninu ile rẹ lailai.

33 Ọkọnrin ti iṣe tirẹ, ẹniti emi kì yio ke kuro ni ibi pẹpẹ mi, yio wà lati ma pọn ọ loju, lati ma bà ọ ninu jẹ; gbogbo iru ọmọ ile rẹ ni yio kú li abọ̀ ọjọ wọn.

34 Eyi li o jẹ àmi fun ọ, ti yio wá si ori ọmọ rẹ mejeji, si ori Hofni ati Finehasi, ni ọjọ kanna li awọn mejeji yio kú.

35 Emi o gbe alufa olododo kan dide, ẹniti yio ṣe gẹgẹ bi ifẹ inu mi, ati ọkàn mi; emi o si kọ ile kan ti yio duro ṣinṣin fun u; yio si ma rin niwaju ẹni-ororo mi li ọjọ gbogbo.

36 Yio si ṣe, olukuluku ẹniti o ba kù ni ile rẹ yio wá tẹriba fun u nitori fadaka diẹ, ati nitori okele onjẹ, yio si wipe, Jọwọ, fi mi sinu ọkan ninu iṣẹ awọn alufa, ki emi ki o le ma ri akara diẹ jẹ.

## ORI 3.

ỌMỌ na Samueli nṣe iranṣẹ fun Oluwa niwaju Eli. Ọrọ Oluwa si ṣọwọ́n lọjọ wọnni; ifihàn kò pọ̀.

2 O si ṣe li akoko na, Eli si dubulẹ ni ipo tirẹ, oju rẹ̀ bẹrẹ̀ si ṣõkun, tobẽ ti ko le riran.

3 Ki itana Ọlọrun to kú ninu tempeli

Digitized by Google

Oluwa, Samueli dubulẹ nibiti apoti Ọlọrun
gbe wà,
4 Oluwa pè Samueli: on si dahun pe,
Emi nĭ.
5 O si sare tọ Eli, o si wipe, Emi nĭ;
nitori ti iwọ pè mi. On wipe, emi kò pè:
pada lọ dubulẹ. O si lọ dubulẹ.
6 Oluwa si tun npè, Samueli. Samueli
si dide tọ Eli lọ, o si wipe, emi nĭ; nito-
riti iwọ pè mi. O si da a lohun, emi kò
pè, ọmọ mi; padà lọ dubulẹ.
7 Samueli ko iti mọ̀ Oluwa, bẽni a ko
iti fi ọ̀rọ Oluwa hàn a.
8 Oluwa si tun Samueli pè lẹ̃kẹta. O
si didé tọ Eli lọ, o si wipe, emi nĭ; nitori
iwọ pè mi. Eli, si mọ̀ pe, Oluwa li o npe
ọmọ na.
9 Nitorina Eli wi fun Samueli pe, Lọ
dubulẹ: yio si ṣe, bi o ba pè ọ, ki iwọ si
wipe, ma wi, Oluwa; nitoriti iranṣẹ rẹ
ngbọ́. Bẽni Samueli lọ, o si dubulẹ nipò
tirẹ̀.
10 Oluwa wá, o si duro, o si pè bi igbá
ti o kọja, Samueli, Samueli. Nigbana ni
Samueli dahun pè, Ma wi; nitori ti iranṣẹ
rẹ ngbọ́.
11 Oluwa si wi fun Samueli pe, Kiyesi i,
emi o ṣe ohun kan ni Israeli, eyi ti yio mu
eti mejejĭ olukuluku awọn ti o gbọ́ ọ ho.
12 Li ọjọ na li emi o mu gbogbo ohun
ti mo ti sọ si ile Eli ṣẹ: nigbati mo ba
bẹrẹ, emi o si ṣe e de opin.
13 Nitoriti emi ti wi fun u pe, emi o san
ẹsan fun ile Eli titi lai, nitori ìwa buburu
ti on mọ̀, nitori awọn ọmọ rẹ̀ ti sọ ara wọn
di ẹni ẹgàn, on kò si da wọn lẹkun.
14 Nitorina emi ti bura si ile Eli, pe
ìwa-buburu ile Eli li a kì yio fi ẹbọ tabi
ọrẹ wẹ̀nù lailai.
15 Samueli dubulẹ titi di owurọ, o si ṣi
ilẹkun ile OLUWA. Samueli si bẹru lati rò
ifihan na fun Eli.
16 Nigbana ni Eli pe Samueli, o si wipe,
Samueli, ọmọ mi. On si dahun pe, Emi nĭ.
17 O si wipe, Kili ohun na ti Oluwa sọ
fun ọ? emi bẹ ọ máṣe pa a mọ fun mi: ki
Ọlọrun ki o ṣe bẹ̃ si ọ, ati jù bẹ̃ lọ pẹlu, bi
iwọ ba pa ohun kan mọ fun mi ninu gbo-
gbo ohun ti o sọ fun ọ.
18 Samueli si rò gbogbo ọ̀rọ na fun u,
kò si pa ohun kan mọ fun u. O si wipe,
Oluwa ni: jẹ ki o ṣe eyi ti o dara li oju rẹ̀.
19 Samueli ndagba, Oluwa si wà pẹlu
rẹ̀, kò si jẹ ki ọkan ninu ọ̀rọ rẹ̀ wọnni bọ́
silẹ.
20 Gbogbo Israeli lati Dani titi o fi de
Beerṣeba mọ̀ pe a ti fi Samueli kalẹ ni woli
fun Oluwa.
21 Oluwa si nfi ara hàn a ni Ṣilo: nito-
riti Oluwa ti fi ara rẹ̀ han fun Samueli ni
Ṣilo nipa ọ̀rọ Oluwa.

ORI 4.

Ọ̀RỌ Samueli si wá si gbogbo Israeli:
Israeli si jade lọ pade awọn Filistini
lati jagun, nwọn do si eti Ebeneseri: awọn
Filistini si do ni Afeki.
2 Awọn Filistini si tẹ itẹgun lati pade
Israeli: nigbati nwọn pade ija, awọn
Filistini si le Israeli: nwọn si pa iwọn
ẹgbaji ọkọnrin ni itẹgun ni pápá.
3 Awọn enia si de budo, awọn agbà
Israeli si wipe, Nitori kini Oluwa ṣe le wa
loni niwaju awọn Filistini? Ẹ jẹ ki a mu
apoti majẹmu Oluwa ti mbẹ ni Ṣilo sọdọ
wa, pe, nigbati o ba de arin wa, ki o le
gba wa kuro lọwọ awọn ọta wa.
4 Bẹli awọn enia si ranṣẹ si Ṣilo, pe ki
nwọn gbe lati ibẹ wá apoti majẹmu Oluwa
awọn ọmọ-ogun ẹniti o joko larin awọn
kerubu: ati awọn ọmọ Eli mejeji, Hofni
ati Finehasi, wà nibẹ pẹlu apoti majẹmu
Ọlọrun.
5 Nigbati apoti majẹmu Oluwa de budo,
gbogbo Israeli si ho yè, tobẹ̃ ti ilẹ mì.
6 Nigbati awọn Filistini si gbọ́ ohùn
ariwo na, nwọn si wipe, Ohùn ariwo nla
kili eyi ni budo awọn Heberu? O si wa
ye wọn pe, apoti majẹmu Oluwa li o de
budo.
7 Ẹru si ba awọn Filistini, nwọn si wipe,
Ọlọrun wọ budo. Nwọn si wipe, Awa
gbe! nitoripe iru nkan bayi kò si ri.
8 A gbe! tani yio gbà wa lọwọ Ọlọrun
alagbara wọnyi? awọn wọnyi li Ọlọrun
ti o fi gbogbo ipọnju pọn Egipti loju li
aginju.
9 Ẹ jẹ alagbara, ẹ ṣe bi ọkọnrin, ẹnyin
Filistini, ki ẹnyin máṣe ẹrú fun awọn
Heberu, bi nwọn ti nṣe ẹrú nyin ri: Ẹ ṣe
bi ọkọnrin, ki ẹ si ja.
10 Awọn Filistini si ja, nwọn si lé
Israeli, nwọn si sa olukuluku sinu ago rẹ̀:
ipani si pọ̀ gidigidi, awọn ẹlẹsẹ ti o ṣubu
ninu ogun Israeli jẹ ẹgbãmẹdogun.
11 Nwọn si gbà apoti-ẹri Ọlọrun: ọmọ
Eli mejeji si kú, Hofni ati Finehasi.
12 Ọkọnrin ara Benjamini kan sa lati
ogun wá o si wá si Ṣilo lọjọ kanna, ti on ti
aṣọ rẹ̀ fifaya, ati erupẹ lori rẹ̀.
13 Nigbati o si de, si wõ, Eli joko lori
apoti kan lẹba ọ̀na o nṣona: nitori aiyà rẹ̀

Digitized by Google

kò balę nitori apoti Qlǫrun. Qkǫnrin na
si wǫ ilu lati rohin, gbogbo ilu fi igbe ta.
14 Eli si gbǫ́ ohùn igbe na, o si wipe,
Ohùn igbe kili eyi? ǫkǫnrin na si yara wá
o si rò fun Eli.
15 Eli si di ęni ejidilǫgǫrun ǫdun; oju
rę̀ di baibai, kò si le riran.
16 Qkǫnrin na si wi fun Eli pe, Emi li
ęniti o ti ogun wá, loni ni mo sa ti ogun
na wá; o si bi i pe, Eti ri, ǫmǫ mi?
17 Ęniti o mu ihin wá si dahun o si
wipe, Israeli sa niwaju awǫn Filistini,
işubu na si pǫ ninu awǫn enia, ati awǫn
ǫmǫ rę mejeji, Hofni ati Finehasi si kú,
nwǫn si gbà apoti Qlǫrun.
18 O si şe, nigbati o darukǫ apoti Qlǫ-
run, o şubu sęhin kuro lori apoti lęba bode,
ǫrùn rę̀ si şę, o si kú: nitori o di arugbo
tan, o si tobi. O si şe idajǫ Israeli li ogoji
ǫdun.
19 Aya ǫmǫ rę̀, obirin Finehasi, loyun,
o si sunmǫ ǫjǫ ibi rę̀; nigbati o si gbǫ́ ihìn
pe a ti gbà apoti Qlǫrun, ati pe, baba ǫkǫ
rę̀ ati ǫkǫ rę̀ kú, o kunlę, o si bimǫ, nitori
obí tę̀ ę.
20 Lakoko ikú rę̀ awǫn obirin ti o duro
tì i si wi fun u pe, Má bęru; nitoriti iwǫ
bi ǫmǫkǫnrin kan. Kò dahun, kò si kà
a si.
21 On si pe ǫmǫ na ni Ikabodu, wipe,
Kò si ogo fun Israeli mǫ: nitoriti a ti gbà
apoti Qlǫrun, ati nitori ti baba ǫkǫ rę̀ ati ti
ǫkǫ rę̀.
22 O si wipe, Ogo kò si fun Israeli mǫ:
nitoriti a ti gbà apoti Qlǫrun.

## ORI 5.

AWǪN Filistini si gbe Apoti Qlǫrun,
nwǫn si mu u lati Ebeneseri wá si
Aşdodu.
2 Nigbati awǫn Filistini gbe apoti Qlǫ-
run, nwǫn si gbe e wá si ile Dagoni, nwǫn
gbe e kà ilę li ęba Dagoni.
3 Nigbati awǫn ara Aşdodu ji li owurǫ
ǫjǫ keji, kiye si i, Dagoni ti şubu dojubolę
niwaju apoti Oluwa. Nwǫn si gbe Dagoni,
nwǫn si tun fi i si ipò rę̀.
4 Nigbati nwǫn ji li owurǫ̀ ǫjǫ keji,
kiyesi i, Dagoni ti şubu dojubolę niwaju
apoti Oluwa; ati ori Dagoni ati atęlę ǫwǫ́
rę̀ mejeji ke kuro li oju ǫ̀na; Dagoni şa li
o kù fun ara rę̀.
5 Nitorina awǫn alufa Dagoni, ati gbo-
gbo awǫn ti ima wá si ile Dagoni, kò si tę
oju ǫ̀na Dagoni ni Aşdodu titi di oni.
6 Qwǫ́ Oluwa si wuwo si ara Aşdodu, o
si pa wǫn run, o si fi iyǫdi pǫn wǫn loju,
ani Aşdodu ati agbegbe rę̀.
7 Nigbati awǫn enia Aşdodu ri pe bę̃ li
o ri, nwǫn si wi pe, Apoti Qlǫrun Israeli
kì yio ba wa gbe: nitoripe ǫwǫ́ rę̀ wuwo si
wa, ati si Dagoni ǫlǫrun wa.
8 Nwǫn ranşę nitorina, nwǫn si pè gbo-
gbo awǫn ijoye Filistini sǫdǫ wǫn, nwǫn
bere pe, Awa o ti şe apoti Qlǫrun Israeli
si? Nwǫn si dahun pe, Ę ję ki a gbe apoti
Qlǫrun Israeli lǫ si Gati. Nwǫn si gbe
apoti Qlǫrun Israeli na lǫ sibę.
9 O si şe pe, lęhin igbati nwǫn gbe e lǫ
tan, ǫwǫ́ Oluwa si wà si ilu na pęlu iparun
nla, o si pǫn awǫn enia ilu na loju, ati
ǫmǫde ati agbà, nwǫn ni iyǫdi.
10 Nitorina nwǫn rán apoti Qlǫrun lǫ
si Ekronu. O si şe, bi apoti Qlǫrun ti
de Ekronu, bę̃li awǫn enia Ekronu kigbe
wipe, nwǫn gbe apoti Qlǫrun Israeli tǫ̀ ni
wá, lati pa wa, ati awǫn enia wa.
11 Bę̃ni nwǫn ranşę, nwǫn si pe gbogbo
ijoye Filistini jǫ, nwǫn si wipe, Rán apoti
Qlǫrun Israeli lǫ, ki ę si ję ki o tun pada
lǫ si ipò rę̀, ki o má ba pa wa, ati awǫn
enia wa: nitoriti ipaiya ikú ti wà ri gbo-
gbo ilu na; ǫwǫ́ Qlǫrun si wuwo gidigidi
ni ibę.
12 Awǫn ǫmǫkǫnrin ti kò kú 'li a si fi
iyǫdi pǫn loju: igbe ilu na si lǫ soke ǫrun.

## ORI 6.

APOTI Oluwa wà ni ilę awǫn Filistini li
oşu meje.
2 Awǫn Filistini si pe awǫn alufa ati
awǫn alasǫtęlę, wipe, Awa o ti şe apoti
Oluwa si? sǫ fun wa ohun ti awa o fi rán
a lǫ si ipò rę̀.
3 Nwǫn si wipe, Bi ęnyin ba rán apoti
Qlǫrun Israeli lǫ, máşe rán a lǫ lofo;
şugbǫn bi o ti wu ki o ri, ę şe irubǫ ębi
fun u; a o si mu nyin lara da, ęnyin o si
mǫ̀ ohun ti o şe ti ǫwǫ́ rę̀ kò fi kuro li ara
nyin.
4 Nwǫn wipe, Kini irubǫ na ti a o fi fun
u? Nwǫn si dahun pe, Iyǫdi wura marun,
ati ę̀liri wura marun, gęgę bi iye ijoye
Filistini: nitoripe ajakalę arùn kanna li o
wà li ara gbogbo nyin, ati awǫn ijoye nyin.
5 Nitorina ęnyin o ya ere iyǫdi nyin, ati
ere ę̀liri nyin ti o bà ilę na ję; ęnyin o si
fi ogo fun Qlǫrun Israeli: bǫya yio mu
ǫwǫ́ rę̀ fęrę lara nyin, ati lara awǫn ǫlǫrun
nyin, ati kuro lori ilę nyin,
6 Nję ẽtişe ti ęnyin fi se aiya nyin le, bi
awǫn ara Egipti ati Farao ti se aiya wǫn

Digitized by Google

le? nigbati o şişę iyanu nla larin wọn,
nwọn kò ha ję ki awọn enia na lọ bi?
nwọn si lọ.
7 Nitorina ę şe kękę titun kan nisisiyi,
ki ę si mu abo malu meji ti o nfi ọmu fun
ọmọ, eyi ti kò ti igbà ajaga si ọrun ri, ki
ę si so o mọ kękę na, ki ẹnyin ki o si mu
ọmọ wọn kuro lọdọ wọn wá ile.
8 Ki ẹnyin ki o si gbe apoti Oluwa nì
ka ori kękę na, ki ẹnyin ki o si fi ohun elo
wura wọnni ti ẹnyin dá fun u nitori ẹbọ
ọrẹ irekọja, ninu apoti kan li apakan rę;
ki ẹnyin rán a, yio si lọ.
9 Ki ę si kiyesi i, bi o ba lọ si ọ̀na
agbegbe tirę si Betşemeşi, a ję pe on na li
o şe wa ni buburu yi: şugbọn bi kò ba şe
bẽ, nigbana li awa o to mọ̀ pe, ki işe ọwọ́
rę li o lù wa, şugbọn ẽşi li o şe si wa.
10 Awọn ọkọnrin na si şe bẽ: nwọn si
mu abo malu meji; ti nfi ọmu fun ọmọ,
nwọn si dè wọn mọ kękę na, nwọn si se
ọmọ wọn mọ ile.
11 Nwọn gbe apoti Oluwa wa lori kękę
na, apoti pẹlu ẹ̀liri wura na, ati ere iyọdí
wọn.
12 Awọn abo malu na si lọ tàra si ọ̀na
Betşemeşi, nwọn si nke bi nwọn ti nlọ li
ọ̀na opopo, nwọn kò yà si ọtún tabi si osì;
awọn ijoye Filistini tẹle wọn lọ si agbegbe
Betşemeşi.
13 Awọn ara Betşemeşi nkore alikama
wọn li afonifoji: nwọn gbe oju wọn soke,
nwọn si ri apoti na, nwọn si yọ̀ lati ri i.
14 Kękę na si wọ inu oko Joşua, ara
Betşemeşi, o si duro nibẹ, ibi ti okuta nla
kan gbe wà: nwọn la igi kękę na, nwọn si
fi malu wọnni ru ẹbọ sisun si Oluwa.
15 Awọn ọmọ Lefi si sọ apoti Oluwa na
kalẹ, ati apoti ti o wà pẹlu rę, nibiti ohun-
elo wura wọnni gbe wà, nwọn si fi le ori
okuta nla na: awọn ọkọnrin Betşemeşi si
ru ẹbọ sisun ati ẹbọ si Oluwa li ọjọ na.
16 Nigbati awọn ijoye Filistini marun si
ri i, nwọn tun yipada lọ si Ekroni li ọjọ
kanna,
17 Wọnyi ni iyọdi wura ti awọn Filistini
da fun irubọ si Oluwa; ọkan ti Aşdodu,
ọkan ti Gasa, ọkan ti Aşkeloni, ọkan ti
Gati, ọkan ti Ekroni.
18 Ẹliri wura na si ri gẹgẹ bi iye gbogbo
ilu awọn Filistini ti o jasi ti awọn ijoye
marun na, ati ilu, ati ilu olodi, ati awọn
ileto, titi o fi de ibi okuta nla Abeli, lori
eyi ti nwọn gbe apoti Oluwa kà: okuta
eyiti o wà titi di oni ninu oko Joşua ara
Betşemeşi.
19 On si pọn awọn ọkọnrin Betşemeşi
loju, nitoriti nwọn bẹ inu apoti Oluwa wò,
iye wọn ti o pa ninu awọn enia na jẹ ẹgbã
mẹdọgbọn o le ãdọrin ọkọnrin, awọn enia
na pohunrere ẹkun nitoriti Oluwa fi iparun
nla pa ọpọ̀ awọn enia na run.
20 Awọn ọkọnrin Betşemeşi si wipe,
Tani yio le duro niwaju Oluwa Ọlọrun
mimọ́ yi? ati lọdọ tani yio lọ bi o kuro
lọdọ wa?
21 Nwọn ran awọn onşẹ si awọn ara
Kirjatjearimu wipe, Awọn Filistini mu
apoti Oluwa wá; ẹ sọkalẹ wá, ki ẹ gbe e lọ
sọdọ nyin.

## ORI 7.

AWỌN ọkọnrin Kirjatjearimu wá, nwọn
gbe apoti Oluwa na, nwọn si mu u wá
si ile Abinadabu ti o wà lori oke, nwọn si
ya Eleasari ọmọ rẹ̀ si mimọ́ lati ma tọju
apoti Oluwa.
2 O si şe, lati igba ti apoti Oluwa fi wà
ni Kirjatjearimu, ọjọ na pẹ́; o si jẹ ogun
ọdun: gbogbo ile Israeli si pohunrere ẹkun
si Oluwa.
3 Samueli si sọ fun gbogbo ile Israeli,
wipe, Bi ẹnyin ba fi gbogbo ọkàn nyin
yipada si Oluwa, ẹ mu ajeji ọlọrun wọnni,
ati Aştaroti kuro larin nyin, ki ẹnyin ki o
si pese ọkàn nyin silẹ fun Oluwa, ki ẹ si
ma sin on nikanşoşo: yio si gbà nyin lọwọ́
awọn Filistini.
4 Awọn ọmọ Israeli si mu Baalimu ati
Aştaroti kuro, nwọn si sìn Oluwa nikan.
5 Samueli si wipe, Pe gbogbo Israeli jọ
si Mispe, emi o si bẹbẹ si Oluwa fun nyin,
6 Nwọn si pejọ si Mispe, nwọn pọn omi,
nwọn si tú u silẹ niwaju Oluwa, nwọn gba-
wẹ li ọjọ na, nwọn si wi nibẹ pe, Awa ti
dẹşẹ si Oluwa. Samueli si şe idajọ awọn
ọmọ Israeli ni Mispe.
7 Awọn Filistini si gbọ́ pe, awọn ọmọ
Israeli pejọ si Mispe, awọn ijoye Filistini
si goke tọ Israeli lọ. Nigbati awọn ọmọ
Israeli gbọ́ ọ, nwọn bẹ̀ru awọn Filistini.
8 Awọn ọmọ Israeli si wi fun Samueli
pe, Máşe dakẹ ati ma ke pe Oluwa Ọlọrun
wa fun wa, yio si gbà wa lọwọ́ awọn Filis-
tini.
9 Samueli mu ọdọ-agutan kan ti nmu
ọmu, o si fi i ru ọtọtọ ẹbọ sisun si Oluwa:
Samueli si ke pe Oluwa fun Israeli; Oluwa
si gbọ́ ọ.
10 Bi Samueli ti nru ẹbọ sisun na lọwọ́,
awọn Filistini si sunmọ Israeli lati ba
wọn jà: şugbọn Oluwa sán ãrá nla li ọjọ

Digitized by Google

na sori awọn Filistini, o si damu wọn, o si
pa wọn niwaju Israeli.
11 Awọn ọkọnrin Israeli si jade kuro ni
Mispe, nwọn si le awọn Filistini, nwọn si
npa wọn titi nwọn fi de abẹ Betkari.
12 Samueli si mu okuta kan, o si gbe e
kalẹ lagbedemeji Mispe ati Seni, o si pe
orukọ rẹ̀ ni Ebeneseri, wipe, Titi de ihin
li Oluwa ràn wa lọwọ́.
13 Bẹ̃li a tẹ ori awọn Filistini ba, nwọn
kò si tun wá si agbegbe Israeli mọ: ọwọ́
Oluwa si wà ni ibi si awọn Filistini, ni
gbogbo ọjọ Samueli.
14 Ilu wọnni eyi ti awọn Filistini ti gbà
lọwọ Israeli ni nwọn si fi fun Israeli, lati
Ekroni wá titi o fi de Gati; ati agbegbe rẹ̀,
ni Israeli gbà silẹ lọwọ́ awọn Filistini. Irẹ-
pọ si wà larin Israeli ati awọn Amori.
15 Samueli ṣe idajọ Israeli ni gbogbo
ọjọ rẹ̀.
16 Lati ọdun de ọdun li on ima lọ yika
Beteli, ati Gilgali, ati Mispe, on si ṣe idajọ
Israeli ni gbogbo ibẹ wọnni.
17 On a si ma yipada si Rama: nibẹ ni
ile rẹ̀ gbe wà; nibẹ na li on si ṣe idajọ Is-
raeli, o si tẹ pẹpẹ nibẹ fun Oluwa.

## ORI 8.

O SI ṣe, nigbati Samueli di arugbo, on si
fi awọn ọmọ rẹ̀ jẹ onidajọ fun Israeli.
2 Orukọ akọbi rẹ̀ njẹ Joeli; orukọ ekeji
rẹ̀ si njẹ Abia: nwọn si nṣe onidajọ ni
Beerṣeba.
3 Awọn ọmọ rẹ̀ kò si rin ni ìwa rẹ̀, nwọn
si ntọ̀ erekere lẹhin, nwọn ngbà abẹtẹlẹ,
nwọn si nyi idajọ po.
4 Gbogbo awọn agbà Israeli si ko ara
wọn jọ, nwọn si tọ Samueli lọ si Rama,
5 Nwọn si wi fun u pe, Kiye si i, iwọ di
arugbo, awọn ọmọ rẹ kò si rin ni ìwa rẹ:
njẹ fi ẹnikan jẹ ọba fun wa, ki o le ma ṣe
idajọ wa, bi ti gbogbo orilẹ-ède.
6 Ṣugbọn ohun na buru loju Samueli,
nitori ti nwọn wipe, Fi ọba fun wa ki o le
ma ṣe idajọ wa, Samueli si gbadua si
Oluwa.
7 Oluwa si wi fun Samueli pe, Gbọ́ ohùn
awọn enia na ni gbogbo eyi ti nwọn sọ fun
ọ: nitoripe iwọ ki nwọn kọ̀, ṣugbọn emi ni
nwọn kọ̀ lati jẹ ọba lori wọn.
8 Gẹgẹ bi gbogbo iṣe ti nwọn ṣe lati ọjọ
ti mo ti mu nwọn jade ti Egipti wá, titi o
si fi di oni, bi nwọn ti kọ̀ mi silẹ, ti nwọn
si nsin awọn ọlọrun miran, bẹ̃ni nwọn ṣe si
ọ pẹlu.
9 Njẹ nitorina gbọ́ ohùn wọn: ṣugbọn
lẹhin igbati iwọ ba ti jẹri si wọn tan, ni-
gbana ni ki iwọ ki o si fi iwà ọba ti yio jẹ
lori wọn hàn wọn.
10 Samueli si sọ gbogbo ọ̀rọ Oluwa fun
awọn enia na ti o mbere ọba lọwọ́ rẹ̀.
11 O si wipe, Eyi ni yio ṣe ìwa ọba na ti
yio jẹ lori nyin: yio mu awọn ọmọkọnrin
nyin, yio si yàn wọn fun ara rẹ̀ fun awọn
kẹkẹ́ rẹ̀, ati fun ẹlẹṣin rẹ̀, nwọn o si ma
sare niwaju kẹkẹ́ rẹ̀.
12 Yio si yan olori ẹgbẹgbẹrun fun ara
rẹ̀, ati olori aradọta; yio si yàn wọn lati
ma ro oko rẹ̀, ati lati ma kore fun u, ati
lati ma ṣe ohun elo-ogun rẹ̀, ati ohun elo-
kẹkẹ́ rẹ̀.
13 On o si mu ninu ọmọbirin nyin ṣe
olusè ikunra õrun didùn, ati ẹniti yio ma
ṣe alasè, ati ẹniti yio ma ṣe akara.
14 Yio mu ninu oko nyin, ati ninu ọgba
ajara nyin, ati ninu igi olifi nyin wọnni,
ani eyiti o dara julọ ninu wọn, yio si fi fun
awọn ẹrú rẹ̀.
15 On o si mu idamẹwa ninu irugbin
nyin, ati ọgbà ajara nyin, yio si fi fun
awọn ẹmẹ̀wa rẹ̀ ati fun awọn ẹrú rẹ̀.
16 Yio mu awọn ẹrúkọnrin nyin, ati
ẹrubirin nyin, ati awọn aṣàyàn ọdọmọkọn-
rin nyin, ati awọn kẹtẹkẹtẹ nyin, yio si fi
nwọn si iṣẹ ara rẹ̀.
17 On o si mu idamẹwa ninu awọn agu-
tan nyin: ẹnyin o si jasi ẹrú rẹ̀.
18 Ẹnyin o kigbe fun igbala li ọjọ na
nitori ọba nyin ti ẹnyin o yàn: Oluwa ki
yio gbọ́ ti nyin li ọjọ na.
19 Ṣugbọn awọn enia na kọ̀ lati gbọ́
ohùn Samueli; nwọn si wipe, bẹ̃kọ; awa o
ni ọba lori wa;
20 Ani awa o si dabi gbogbo orilẹ-ède;
ki ọba wa ki o si ma ṣe idajọ wa, ki o si ma
ṣaju wa, ki o si ma ja ogun wa.
21 Samueli si gbọ́ gbogbo ọ̀rọ awọn enia
na, o si sọ wọn li eti Oluwa.
22 Oluwa si wi fun Samueli pe, Gbọ́
ohùn wọn ki o si fi ọba jẹ fun wọn.
Samueli sọ fun awọn ọmọ Israeli pe, Lọ,
olukuluku si ilu rẹ̀.

## ORI 9.

NJẸ ọkọnrin kan ara Benjamini si wà, a
ma pe orukọ rẹ̀ ni Kiṣi, ọmọ Abeli,
ọmọ Sesori, ọmọ Bekorati, ọmọ Afia, ara
Benjamini ọkọnrin alagbara.
2 On si ni ọmọkọnrin kan, ẹniti a npè
ni Saulu, ọdọmọkọnrin ti o yàn ti o si ṣe

Digitized by Google

arẹwa, kò si si ẹniti o dara ju u lọ ninu
gbogbo awọn ọmọ Israeli: lati ejika rẹ̀ lọ
si oke, o ga jù gbogbo awọn enia na lọ.
3 Kẹtẹkẹtẹ Kiṣi baba Saulu si nù. Kiṣi
si wi fun Saulu ọmọ rẹ̀ pe, Jọwọ mu ọkan
ninu awọn iranṣẹkọnrin pẹlu rẹ, ki o si
dide lọ wá kẹtẹkẹtẹ wọnni.
4 On kọja niha oke Efraimu, o si kọja
niha ilẹ Saliṣa, ṣugbọn nwọn kò ri wọn:
nwọn si kọja ni ilẹ Salimu, nwọn kò si si
nibẹ; o si kọja ni ilẹ Benjamini, nwọn kò
si ri wọn.
5 Nigbati nwọn de ilẹ Sufu, Saulu wi
fun iranṣẹ-kọnrin rẹ̀ ẹniti o wà lọdọ rẹ̀, pe,
Wá, jẹ ki a yipada; ki baba mi ki o má
ba fi ãjò awọn kẹtẹkẹtẹ silẹ, ki o si ma kọ
ominu nitori wa.
6 O si wi fun u pe, Kiye si i, ẹni Ọlọrun
kan wà ni ilu yi, o si ṣe ọkọnrin ọlọla;
gbogbo eyi ti o ba wi, a si ṣẹ: wá, ki a
lọ si ibẹ̀; bọya yio fi ọ̀na ti a o gbà hàn
wa.
7 Saulu si wi fun iranṣẹ rẹ̀ pe, Bi awa
ba lọ, kili awa o mu lọ fun ọkọnrin na?
nitoripe akara tan ni apò wa, ko si si
ọrẹ ti a o mu tọ̀ ẹni Ọlọrun na: kili
awa ni;
8 Iranṣẹ na si da Saulu lohùn wipe, Mo
ni idamẹrin ṣekeli fadaka lọwọ́, eyi li emi
o fun ẹni Ọlọrun na, ki o le fi ọ̀na wa
hàn wa.
9 (Ni Israeli latijọ, nigbati ọkọnrin kan
ba lọ bere lọdọ Ọlọrun, bayi ni ima wi,
Wá, ẹ jẹ ki a lọ sọdọ arina na, nitori ẹni ti
a npe ni woli nisisiyi, on ni a npe ni arina
nigba atijọ ri.)
10 Nigbana ni Saulu wi fun iranṣẹ rẹ̀ pe,
Iwọ wi rere; wá, jẹ ki a lọ. Bẽni nwọn
si lọ si ilu na nibiti ẹni Ọlọrun nã gbe
wà.
11 Bi nwọn ti nlọ si oke ilu na, nwọn ri
awọn wundia ti nlọ fa omi, nwọn bi wọn
lere wipe, Arina mbẹ nihin bi?
12 Nwọn si da wọn lohùn, nwọn si wipe,
O mbẹ; wo o, o mbẹ niwaju nyin: yara
nisisiyi nitoripe loni li o de ilu; nitoriti
ẹbọ mbẹ fun awọn enia loni ni ibi giga.
13 Bi ẹnyin ti nlọ si ilu na, ẹnyin o si ri
i, ki o to lọ si ibi giga lati jẹun: nitoripe
awọn enia kì yio jẹun titi on o fi de, nitori
on ni yio sure si ẹbọ na; lẹhin eyini li
awọn ti a pè yio to jẹun. Ẹ goke lọ nisisiyi;
lakoko yi ẹnyin o ri i.
14 Nwọn goke lọ si ilu na: bi nwọn si
ti nwọ ilu na, kiye si i, Samueli mbọ̀ wá
pade wọn, lati goke lọ si ibi giga na,
15 Oluwa ti wi leti Samueli ni ijọ kan
ki Saulu ki o to de, wipe,
16 Niwoyi ọla emi o ran ọkọnrin kan
lati ilẹ Benjamini wá si ọ, iwọ o si da ororo
si i lori ki o le jẹ olori-ogun Israeli awọn
enia mi, yio si gbà awọn enia mi là lọwọ
awọn Filistini: nitori emi ti bojuwo awọn
enia mi, nitoripe ẹkun wọn ti de ọdọ mi.
17 Nigbati Samueli ri Saulu, Oluwa wi
fun u pe, Wo ọkọnrin na ti mo ti sọrọ rẹ̀
fun ọ! on ni yio jọba awọn enia mi.
18 Saulu si sunmọ Samueli li ẹnu-ọna
ilu, o si wipe, Sọ fun mi, emi bẹ ọ, nibo ni
ile arina gbe wà?
19 Samueli da Saulu lohùn o si wipe,
emi ni arina na: goke lọ siwaju mi ni ibi
giga, ẹ o si ba mi jẹun loni, li owurọ̀ emi o
si jẹ ki o lọ, gbogbo eyi ti o wà li ọkàn rẹ
li emi o sọ fun ọ.
20 Niti awọn kẹtẹkẹtẹ rẹ ti o ti nù lati
iwọn ijọ mẹta wá, má fi ọkàn si wọn;
nitoriti nwọn ti ri wọn. Si tani gbogbo
ifẹ Israeli wà? Ki iṣe si ọ ati si ile baba
rẹ?
21 Saulu si dahùn o si wipe, Ara Ben-
jamini ki emi iṣe? kekere ninu ẹya Israeli?
idile mi kò si rẹhìn ninu gbogbo ẹya Ben-
jamini? ẽsi ti ṣe ti iwọ sọrọ yi si mi?
22 Samueli si mu Saulu ati iranṣẹ rẹ̀, o
si mu wọn wọ inu gbàngàn, o si fun wọn
ni ijoko lãrin awọn agbagba ninu awọn ti
a pè, nwọn si to ọgbọ̀n enia.
23 Samueli si wi fun alase pe, Mu ipin
ti mo ti fi fun ọ wá, eyi ti mo ti sọ fun ọ
pe, Ki o fi i pamọ sọdọ rẹ.
24 Alase na si gbe ejika na, ati eyi ti o
wà lori rẹ̀, o si gbe e kalẹ niwaju Saulu.
Samueli si wipe, Wo eyi ti a fi silẹ! fà a
sọdọ rẹ, ki o si ma jẹ: nitoripe titi di isisiyi
li ati pa a mọ fun ọ lati igbati mo ti wipe,
emi ti pe awọn enia na. Bẽni Saulu si ba
Samueli jẹun li ọjọ na.
25 Nigbati nwọn sọkalẹ lati ibi giga nì
wá si ilu, Samueli si ba Saulu sọrọ lori
orule.
26 Nwọn si dide ni kutukutu: o si ṣe,
li afẹmọjumọ, Samueli si pe Saulu sori
orule, wipe, Dide, emi o si ran ọ lọ. Saulu
si dide, awọn mejeji si jade, on ati Samueli,
si gbangba.
27 Bi nwọn si ti nsọkalẹ lọ si ipẹkun ilu
na, Samueli wi fun Saulu pe, Wi fun iranṣẹ
ki o kọja si iwaju wa, (o si kọja) ṣugbọn ki
iwọ ki o duro diẹ, ki emi ki o lo fi ọ̀rọ
Ọlọrun hàn ọ.

Digitized by Google

## ORI 10.

SAMUELI si mu igo ororo, o si tu u si i li ori, o si fi ẹnu kò o li ẹnu, o si wipe, Kò ṣepe nitoriti Oluwa ti fi ororo yàn ọ li olori ini rẹ̀?

2 Nigbati iwọ ba lọ kuro lọdọ mi loni, iwọ o ri ọkọnrin meji li ẹba iboji Rakeli li agbegbe Benjamini, ni Selsa; nwọn o si wi fun ọ pe, Nwọn ti ri awọn kẹtẹkẹtẹ ti iwọ ti jade lọ iwá: si wõ, baba rẹ ti fi ọran ti kẹtẹkẹtẹ silẹ, o si kọ omnu nitori rẹ wipe, Kili emi o ṣe niti ọmọ mi?

3 Iwọ o si kọja lati ibẹ lọ, iwọ o si de pẹtẹlẹ Tabori, nibẹ li ọkọnrin mẹta ti nlọ sọdọ Ọlọrun ni Beteli yio pade rẹ, ọkan yio mu ọmọ ewurẹ mẹta lọwọ, ekeji yio mu iṣù akara mẹta, ati ẹkẹta yio mu igo ọti-waini.

4 Nwọn o si ki ọ, nwọn o si fi iṣù akara meji fun ọ; iwọ o si gbà a lọwọ wọn.

5 Lẹhin eyini iwọ o wá si oke Ọlọrun, nibiti ẹgbẹ ogun awọn Filistini wà; yio si ṣe, nigbati iwọ ba de ilu na, iwọ o si pade ẹgbẹ woli ti yio ma sọkalẹ lati ibi giga nì wá; nwọn o si ni psalteri, ati tabreti, ati fère, ati harpu niwaju wọn, nwọn o si ma sọtẹlẹ.

6 Ẹmi Oluwa yio si bà le ọ, iwọ o si ma ba wọn sọtẹlẹ, iwọ o si di ẹlomiran.

7 Yio si ri bẽ, nigbati àmi wọnyi ba de si ọ, ṣe fun ara rẹ ohun gbogbo ti ọwọ́ rẹ ba ri lati ṣe, nitoriti Ọlọrun wà pẹlu rẹ.

8 Iwọ o si ṣaju mi sọkalẹ lọ si Gilgali, si kiye si i, emi o sọkalẹ tọ̀ ọ wá, lati rubọ sisun, ati lati ru ẹbọ irẹpọ̀: ni ijọ meje ni iwọ o duro, titi emi o fi tọ̀ ọ wá, emi o si fi ohun ti iwọ o ṣe han ọ.

9 O si ri bẽ pe, nigbati o yi ẹhin rẹ̀ pada lati lọ kuro lọdọ Samueli, Ọlọrun si fun u li ọkàn miran: gbogbo àmi wọnni si ṣẹ li ọjọ na.

10 Nigbati nwọn si de ibẹ, si oke na, si kiye si i, ẹgbẹ awọn woli pade rẹ̀, Ẹmi Ọlọrun si bà le e, on si sọtẹlẹ larin wọn.

11 O si ṣe, nigbati gbogbo awọn ti o mọ̀ ọ ri pe o nsọtẹlẹ larin awọn woli, awọn enia si nwi fun ara wọn pe, Kili eyi ti o de si ọmọ Kiṣi? Saulu wà ninu awọn wolĩ pẹlu?

12 Ẹnikan lati ibẹ na wá si dahùn, o si wipe, ṣugbọn tani baba wọn? Bẽli o si wà li owe, Saulu wà ninu awọn wolĩ pẹlu?

13 Nigbati o sọtẹlẹ tan, o si lọ si ibi giga nì.

14 Arakọnrin Saulu kan si wi fun u ati fun iranṣẹ rẹ̀ pe, Nibo li ẹnyin ti lọ? On si wipe, lati wá awọn kẹtẹkẹtẹ ni: nigbati awa ri pe nwọn kò si nibi kan, awa si tọ Samueli lọ.

15 Arakọnrin Saulu na si wipe, Sọ fun mi, emi bẹ̀ ọ, ohun ti Samueli wi fun ọ.

16 Saulu si wi fun arakọnrin rẹ̀ pe, On ti sọ fun wa dajudaju pe, nwọn ti ri awọn kẹtẹkẹtẹ nã. Ṣugbọn ọ̀ran ijọba ti Samueli sọ, on kọ̀ sọ fun u.

17 Samueli si pe gbogbo enia jọ siwaju Oluwa ni Mispe.

18 O si wi fun awọn ọmọ Israeli pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi, Emi mu Israeli goke ti Egipti wá, mo si gbà nyin kuro lọwọ́ awọn ara Egipti, ati kuro lọwọ́ gbogbo ijọba wọnni ti o pọn nyin loju.

19 Ẹnyin si kọ̀ Ọlọrun nyin loni, ẹniti on tikara rẹ̀ ti gbà nyin kuro lọwọ́ gbogbo awọn ọta nyin, ati gbogbo wahala nyin; ẹnyin si ti wi fun u pe, Bẽkọ, ṣugbọn awa nfẹ ki o fi ẹnikan jọba lori wa. Nisisiyi ẹ duro niwaju Oluwa nipa ẹyà nyin, ati nipa ẹgbẹgbẹrun nyin.

20 Samueli si mu ki gbogbo ẹya Israeli sunmọ tosi, a si mu ẹya Benjamini.

21 On si mu ki ẹya Benjamini sunmọ tosi nipa idile wọn, a mu idile Matri, a si mu Saulu ọmọ Kiṣi: nigbati nwọn si wá a kiri, nwọn kò si ri i.

22 Nitorina nwọn si tun bere lọdọ Oluwa sibẹ bi ọkọnrin na yio wá ibẹ̀. Oluwa si dahùn wipe, Wõ, o pa ara rẹ̀ mọ lãrin ohunelò.

23 Nwọn sare, nwọn si mu u lati ibẹ̀ wá: nigbati o si duro lãrin awọn enia na, o si ga jù gbogbo wọn lọ lati ejika rẹ̀ soke.

24 Samueli si wi fun gbogbo awọn enia na pe, Ẹnyin kò ri ẹniti Oluwa yàn fun ara rẹ̀, pe, ko si ẹniti o dabi rẹ̀ ninu gbogbo enia na? Gbogbo enia si ho ye, nwọn si wipe, Ki Ọba ki o pẹ!

25 Samueli si sọ iwa ijọba fun awọn enia na. O si kọ ọ sinu iwe, o si fi i siwaju Oluwa. Samueli si rán gbogbo enia na lọ, olukuluku si ile rẹ̀.

26 Saulu pẹlu si lọ si ile rẹ̀ si Gibea; ẹgbẹ awọn alagbara ọkọnrin si ba a lọ, ọkàn awọn ẹniti Ọlọrun tọ́.

27 Ṣugbọn awọn ọmọ Beliali wipe, Ọkọnrin yi yio ti ṣe gbà wa? Nwọn kẹgàn rẹ̀, nwọn ko si mu ọrẹ wá fun u. On si dakẹ.

Digitized by Google

## ORI 11.

NAHAṢI ara Ammoni si goke wá, o si do
ti Jabeṣi - Gileadi: gbogbo ọkọnrin
Jabeṣi si wi fun Nahaṣi, pe, Ba wa da ma-
jẹmu, awa o si ma sìn ọ.
2 Nahaṣi ara Ammoni na si da wọn lohùn
pe, Nipa bayi li emi o fi ba nyin da majẹ-
mu, nipa yiyọ gbogbo oju ọtun nyin kuro,
emi o si fi i ṣe ẹlẹya li oju gbogbo Israeli.
3 Awọn agba Jabeṣi si wi fun u pe, Fun
wa li ayè ni ijọ meje, awa o si ran onṣẹ si
gbogbo agbegbe Israeli bi ko ba si ẹniti yio
gbà wa, awa o si jade tọ ọ wá.
4 Awọn iranṣẹ na si wá si Gibea ti Saulu,
nwọn rohìn na li eti awọn enia: gbogbo
enia na si gbe ohùn wọn soke, nwọn si
sọkun.
5 Si kiye si i, Saulu bọ̀ wá ile lẹhin ọwọ́
malu lati papa wá; Saulu si wipe, Ẽṣe
awọn enia ti nwọn fi nsọkun? Nwọn si sọ
ọ̀rọ awọn ọkọnrin Jabeṣi fun u.
6 Ẹmi Ọlọrun si bà le Saulu nigbati o
gbọ́ ọ̀rọ wọnni, inu rẹ̀ si ru pipọ.
7 O si mu malu meji, o rẹ́ wọn wẹwẹ, o
si ran wọn si gbogbo agbegbe Israeli nipa
ọwọ́ awọn onṣẹ na, wipe, Ẹnikẹni ti o wu
ki o ṣe ti ko ba tọ Saulu ati Samueli lẹhin,
bẽ gẹgẹ li a o ṣe si malu rẹ̀. Ibẹru Oluwa
si mu awọn enia na, nwọn si jade bi enia
kanṣoṣo.
8 O si kà wọn ni Beseki, awọn ọmọ
Israeli si jẹ ọkẹ mẽdogun enia; awọn ọkọn-
rin Juda si jẹ ẹgbã mẽdogun.
9 Nwọn si wi fun awọn iranṣẹ na ti o ti
wá pe, Bayi ni ki ẹ wi fun awọn ọkọnrin
Jabeṣi-Gileadi; Li ọla, lakoko igbati õrùn
ba mu, ẹnyin o ni iranlọwọ. Awọn onṣẹ
na wá, nwọn rò o fun awọn ọkọnrin Jabeṣi;
nwọn si yọ̀.
10 Nitorina awọn ọkọnrin Jabeṣi wi pe,
lọla awa o jade tọ nyin wá, ẹnyin o si fi
wa ṣe bi gbogbo eyi ti o tọ loju nyin.
11 O si ri bẽ lọla na, Saulu si ya awọn
enia na si ẹgbẹ mẹta; nwọn si wá ãrin ogun
na ni iṣọ owurọ̀, nwọn si pa awọn ara Am-
moni titi o fi di igba imoru ọjọ: o si ṣe
awọn iyoku fọnka, tobẽ ti meji wọn ko kù
ni ibi kan.
12 Awọn enia na si wi fun Samueli, pe,
Tani wipe, Saulu yio ha jọba lori wa? mu
awọn ọkọnrin na wá, a o si pa wọn.
13 Saulu si wi pe, a kì yio pa ẹnikẹni
loni yi; nitoripe loni li Oluwa ṣiṣẹ igbala
ni Israeli.
14 Nigbana ni Samueli wi fun awọn enia
na pe, Wá, ki a lọ si Gilgali, ki a le tun
ijọba na ṣe nibẹ.
15 Gbogbo enia na si lọ si Gilgali; nibẹ
ni nwọn gbe fi Saulu jọba niwaju Oluwa ni
Gilgali: nibẹ ni nwọn gbe ru ẹbọ irẹpọ̀ ni-
waju Oluwa; nibẹ ni Saulu ati gbogbo
awọn ọkọnrin Israeli si yọ ayọ̀ nlanla.

## ORI 12.

SAMUELI wi fun gbogbo Israeli pe, Kiye
si i, emi ti gbọ́ ohùn nyin, ninu gbo-
gbo eyi ti ẹnyin wi fun mi, emi si ti fi
ẹnikan jọba lori nyin.
2 Si wõ, nisisiyi, ọba na nrìn niwaju
nyin: emi si ti di arugbo, mo si hewu; si
wõ, awọn ọmọ mi si mbẹ lọdọ nyin: emi
ti nrìn niwaju nyìn lati igba ewe mi wá titi
o fi di oni yi.
3 Wõ, emi nĩ, jẹri si mi niwaju Oluwa,
ati niwaju ẹni ami-ororo rẹ̀: malu tani mo
gbà ri? tabi kẹtẹkẹtẹ tani mo gbà ri? tani
mo rẹjẹ ri? tani mo jẹ ni ìya ri? tabi lọwọ́
tali emi gbà owo abẹtẹlẹ kan ri lati fi bo ara
mi loju? emi o si sãn pada fun nyin.
4 Nwọn si wipe, Iwọ kò rẹ́ wa jẹ ri, bẽni
iwọ kò jẹ ni ni ìya ri, bẽni iwọ ko gbà nkan
lọwọ́ ẹnikẹni wa ri.
5 O si wi fun wọn pe, Oluwa li ẹlẹri si
nyin, ati ẹni ami-ororo rẹ̀ ni ẹlẹri loni pe,
ẹnyin kò ri nkan lọwọ́ mi. Nwọn si dahùn
wipe, On li ẹlẹri.
6 Samueli si wi fun awọn enia na pe,
Oluwa li ẹniti o ti yan Mose ati Aaroni, on
li ẹni ti o si mu awọn baba nyin goke ti ilẹ
Egipti wá.
7 Njẹ nisisiyi ẹ duro jẹ, ki emi ki o le
ba nyin sọ̀rọ niwaju Oluwa niti gbogbo iṣẹ
ododo Oluwa, eyi ti on ti ṣe fun nyin ati
fun awọn baba nyin.
8 Nigbati Jakobu wá si Egipti, ti awọn
baba kigbe pe Oluwa, Oluwa si rán Mose
ati Aaroni, awọn ẹniti o mu awọn baba nyin
ti ilẹ Egipti jade wá, o si mu wọn joko
nihinyi.
9 Nwọn si gbagbe Oluwa Ọlọrun wọn, o
si tà wọn si ọwọ́ Sisera, olori ogun Hasori,
ati si ọwọ́ awọn Filistini, ati si ọwọ́ ọba
Moabu, nwọn si ba wọn jà.
10 Nwọn si kigbe pe Oluwa, nwọn si
wipe, Awa ti dẹṣẹ̀, nitoripe awa ti kọ̀ Olu-
wa silẹ, awa si ti nsin Baalimu ati Aṣtaroti:
ṣugbọn nisisiyi, gba wa lowọ́ awọn ọta wa,
awa o si sìn ọ.
11 Oluwa si ran Jerubbaali, ati Bedani,
ati Jefta ati Samueli, nwọn si gbà nyin

Digitized by Google

lọwọ́ awọn ọta nyin niha gbogbo, ẹnyin si
joko li alafia.
12 Nigbati ẹnyin si ri pe Nahaṣi ọba
awọn ọmọ Ammoni tọ̀ nyin wá, ẹnyin wi
fun mi pe, Bẹ̀kọ, ṣugbọn ọba yio jẹ lori
wa: nigbati Oluwa Ọlọrun nyin jẹ ọba
nyin.
13 Njẹ nisisiyi wo ọba na ti ẹnyin yàn,
ati ti ẹnyin fẹ, kiye si i, Oluwa fi ọba jẹ
fun nyin.
14 Bi ẹnyin ba bẹ̀ru Oluwa, ti ẹnyin si
sin i, ti ẹnyin si gbọ́ ohùn rẹ̀, ti ẹnyin ko
si tapa si ọ̀rọ Oluwa, ẹnyin ati ọba nyin ti
o jẹ lori nyin yio ma wà lẹhin Oluwa
Ọlọrun nyin.
15 Ṣugbọn bi ẹnyin ko ba gbà ohun
Oluwa gbọ́, ti ẹ ba si tàpá si ọ̀rọ Oluwa,
ọwọ́ Oluwa yio wà lara nyin si ibi, bi o ti
wà lara baba nyin.
16 Nitorina nisisiyi ẹ duro ki ẹ si wo
nkan nla yi, ti Oluwa yio ṣe li oju nyin.
17 Oni ki ọjọ ikore ọka bi? emi o kepe
Oluwa, yio si ran ãra ati ojò; ẹnyin o si
mọ̀, ẹnyin o si ri pe iwabuburu nyin pọ̀, ti
ẹnyin ṣe li oju Oluwa ni bibere ọba fun
ara nyin.
18 Samueli si kepe Oluwa, Oluwa si ran
ãra ati ojò ni ọjọ na: gbogbo enia si bẹru
Oluwa pupọ ati Samueli.
19 Gbogbo enia si wi fun Samueli pe,
Gbadura si Oluwa Ọlọrun rẹ fun awọn iran-
ṣẹ rẹ, ki awa ki o má ba kú: nitori ti awa
ti fi buburu yi kun gbogbo ẹṣẹ wa ni bibere
ọba fun ara wa.
20 Samueli si wi fun awọn enia na pe, Ẹ
má bẹ̀ru: ẹnyin ti ṣe gbogbo buburu yi:
sibẹ ẹ má pada lẹhin Oluwa, ẹ ma fi gbo-
gbo ọkàn nyin sin Oluwa.
21 Ẹ máṣe yipada; nitori yio jasi itẹle
ohun asan lẹhin, eyi ti kì yio ni ere; bẽni
kì yio si gbanila; nitori asan ni nwọn.
22 Nitoriti Oluwa kì yio kọ̀ awọn enia
rẹ̀ silẹ nitori orukọ rẹ̀ nla: nitoripe o wu
Oluwa lati fi nyin ṣe enia rẹ̀.
23 Pẹlupẹlu bi o ṣe ti emi ni, ki a má ri
i pe emi si dẹṣẹ̀ si Oluwa ni didẹkun gba-
dura fun nyin: emi o si kọ́ nyin li ọ̀na rere
ati titọ.
24 Ṣugbọn ẹ bẹ̀ru Oluwa, ki ẹ si fi gbo-
gbo ọkàn nyin sin i lododo: njẹ, ẹ ronu
ohun nlanla ti o ṣe fun nyin.
25 Ṣugbọn bi ẹnyin ba hu ìwa buburu
sibẹ, ẹnyin o ṣegbe t'ẹnyin t'ọba nyin.

## ORI 13.

SAULU jọba li ọdun kan; nigbati o si
jọba ọdun meji lori Israeli,
2 Saulu si yan ẹgbẹ̃dogun ọmọkọnrin fun
ara rẹ̀ ni Israeli; ẹgbã si wà lọdọ Saulu ni
Mikmaṣi ati li oke-nla Beteli; ẹgbẹrun si
wà lọdọ Jonatani ni Gibea ti Benjamini; o
si rán awọn enia ti o kù olukuluku si agọ
rẹ̀.
3 Jonatani si pa ẹgbẹ ogun awọn Filisti-
ni ti o wà ninu ile olodi ni Geba, awọn
Filistini si gbọ́. Saulu fun ipè yi gbogbo
ilẹ na ka, wipe, Jẹ ki awọn Heberu gbọ́.
4 Gbogbo Israeli si gbọ́ pe Saulu pa ẹgbẹ
ogun awọn Filistini, Israeli si di irira fun
awọn Filistini. Awọn enia na si pejọ lẹhin
Saulu lati lọ si Gilgali.
5 Awọn Filistini kó ara wọn jọ lati ba
Israeli jà, ẹgbã-mẹ̃dogun kẹkẹ, ẹgbãta
ọkọnrin ẹlẹṣin, enia si pọ̀ bi yanrin leti
okun; nwọn si goke, nwọn do ni Mikmaṣi
ni iha ila õrun Bet-Afeni.
6 Awọn ọkọnrin Israeli si ri pe, nwọn
wà ninu ipọnju (nitoripe awọn enia na wà
ninu ìhamọ) nigbana ni awọn enia na fi ara
pamọ ninu iho, ati ninu panti, ninu apata,
ni ibi giga, ati ninu kanga gbigbẹ.
7 Omiran ninu awọn Heberu goke odo
Jordani si ilẹ Gadi ati Gileadi. Bi o ṣe ti
Saulu, on wà ni Gilgali sibẹ, gbogbo enia
na si nwariri lẹhin rẹ̀.
8 O si duro ni ijọ meje, de akoko ti
Samueli dá fun u; ṣugbọn Samueli kó wá
si Gilgali, awọn enia si tuka kuro li ọdọ rẹ̀.
9 Saulu si wipe, Mu ẹbọ sisun ati ẹbọ
irẹpọ̀ na fun mi wá, o si ru ẹbọsisun na.
10 O si ṣe bi o ti ṣe ẹbọ ọrẹ ati ẹbọ sisun
wọnni pari, si kiye si i, Samueli de; Saulu
si jade lati lọ pade rẹ̀, ki o le ki i.
11 Samueli si bi i pe, Kini iwọ ṣe yi?
Saulu si dahùn pe, Nitoriti emi ri pe awọn
enia na ntuka kuro lọdọ mi, iwọ kò si wá
li akoko ọjọ ti o dá, awọn Filistini si ko
ara wọn jọ ni Mikmaṣi.
12 Nitorina li emi ṣe wipe, Nisisiyi li
awọn Filistini yio sọkalẹ tọ mi wá si Gil-
gali, bẹ̃li emi ko iti tù Oluwa loju; emi si
tì ara mi si i, mo si ru ẹbọ sisun na.
13 Samueli si wi fun Saulu pe, iwọ kò
hu iwà ọlọgbọ́n: iwọ ko pa ofin Oluwa
Ọlọrun rẹ mọ, ti on ti pa li aṣẹ fun ọ: ni-
tori nisisiyi li Oluwa iba fi idi ijọba rẹ kalẹ̀
lori Israeli lailai.
14 Ṣugbọn nisisiyi ijọba rẹ kì yio duro
pẹ: Oluwa ti wá fun ara rẹ̀ ọkọnrin ti o

Digitized by Google

wù u li ọkàn rẹ̀, Oluwa paṣẹ fun u ki o ṣe olori fun awọn enia rẹ̀, nitoripe iwọ kò pa aṣẹ ti Oluwa fi fun ọ mọ.

15 Samueli si dide, o si lọ lati Gilgali si Gibea ti Benjamini. Saulu si ka awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀, o jẹ iwọ̀n ẹgbẹta ọkọnrin.

16 Saulu, ati Jonatani ọmọ rẹ̀, ati awọn enia na ti o wà lọdọ wọn si joko ni Gibea ti Benjamini, ṣugbọn awọn Filistini do ni Mikmaṣi.

17 Ẹgbẹ awọn onisùmọ̀mi mẹta jade ni ibudo awọn Filistini: ẹgbẹ kan gbà ọ̀na ti Ofra, si ilẹ Ṣuali.

18 Ẹgbẹ kan si gba ọ̀na Bet-horoni: ati ẹgbẹ kan si gbà ọ̀na agbegbe nì ti o kọju si afonifoji Seboimu ti o wà ni iha iju.

19 Kò si alagbẹdẹ ninu gbogbo ilẹ Israeli: nitori ti awọn Filistini wipe, Ki awọn Heberu ki o má ba rọ idà tabi ọ̀kọ.

20 Ṣugbọn gbogbo Israeli a ma tọ̀ awọn Filistini lọ, olukuluku lati pọ́n doje rẹ̀, ati ọ̀kọ rẹ̀, ati ãke rẹ̀, ati ọ̀ṣọ rẹ̀.

21 Ṣugbọn nwọn ni ayùn fun ọ̀ṣọ, ati fun ọ̀kọ, ati fun ọ̀ya-irin ti ilẹ, ati fun ãke, ati lati pọn irin ọpa oluṣọ malu.

22 Bẹ̃li o si ṣe li ọjọ ijà, ti a kò ri idà, tabi ọ̀kọ lọwọ ẹnikẹni ninu awọn enia ti o wà lọdọ Saulu ati Jonatani; lọdọ Saulu ati Jonatani ọmọ rẹ̀ li a ri.

23 Awọn ọmọ-ogun Filistini jade lọ si ikọja Mikmaṣi.

## ORI 14.

O SI ṣe li ọjọ kan, Jonatani ọmọ Saulu si wi fun ọdọmọkọnrin ti o nru ihamọra rẹ̀, pe, Wá, jẹ ki a rekọja lọ si ibudo-ogun awọn Filistini ti o wà niha keji. Ṣugbọn on kò sọ fun baba rẹ̀.

2 Saulu si duro ni iha ipinlẹ Gibea labẹ igi ìbo eyi ti o wà ni Migronu: awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀ to iwọn ẹgbẹta ọkọnrin.

3 Ahia ọmọ Ahitubu, arakọnrin Ikabodu ọmọ Finehasi, ọmọ Eli, alufa Oluwa ni Ṣilo, ti nwọ̀ Efodu. Awọn enia na kò si mọ̀ pe Jonatani ti lọ.

4 Larin meji ọ̀na wọnni, eyi ti Jonatani ti nwá lati lọ si ile ọmọ-ogun olodi ti Filistini, okuta mimú kan wà li apa kan, okuta mimú kan si wà li apa keji: orukọ ekini si njẹ Bosesi, orukọ ekeji si njẹ Sene.

5 Ṣonṣo okuta ọkan wà ni ariwa kọju si Mikmaṣi, ti ekeji si wà ni gusù niwaju Gibea.

6 Jonatani wi fun ọdọmọdekọnrin ti o rù ihamọra rẹ̀ pe, Wá, si jẹ ki a lọ si budo-ogun awọn alaikọla yi: bọya Oluwa yio ṣiṣẹ fun wa: nitoripe kò si idiwọ fun Oluwa lati fi pipọ tabi diẹ gba là.

7 Ẹniti o rù ihamọra rẹ̀ na wi fun u pe, Ṣe gbogbo eyi ti o mbẹ li ọkàn rẹ: ṣe bi o ti tọ̀ li ọkàn rẹ; wõ, emi wà pẹlu rẹ gẹgẹ bi ti ọkàn rẹ.

8 Jonatani si wi pe, Kiye si i, awa o rekọja sọdọ awọn ọkọnrin wọnyi, a o si fi ara wa hàn fun wọn.

9 Bi nwọn ba wi fun wa pe, Ẹ duro titi awa o fi tọ̀ nyin wá; awa o si duro, awa kì yio si goke tọ̀ wọn lọ.

10 Ṣugbọn bi nwọn ba wi pe, Goke tọ̀ wa wá; a o si goke lọ: nitori pe Oluwa ti fi wọn le wa lọwọ́; eyi ni o si jẹ àmi fun wa.

11 Awọn mejeji fi ara wọn hàn fun ogun Filistini: awọn Filistini si wipe, Wõ, awọn Heberu ti inu iho wọn jade wá, nibiti nwọn ti fi ara pamọ si.

12 Awọn ọkọnrin ile olodi na si da Jonatani ati ẹniti o rù ihamọra rẹ̀ lohùn, nwọn si wipe, Goke tọ̀ wa wá, awa o si fi nkan hàn nyin; Jonatani si wi fun ẹniti o rù ihamọra rẹ̀ pe, Ma tọ̀ mi lẹhìn; nitoripe Oluwa ti fi wọn le awọn enia Israeli lọwọ.

13 Jonatani rakò goke, ati ẹniti o rù ihamọra rẹ̀ lẹhin rẹ̀; awọn Filistini si ṣubu niwaju Jonatani; ati ẹniti o rù ihamọra rẹ̀ npa lẹhin rẹ̀.

14 Pipa ikini, eyi ti Jonatani ati ẹniti o rù ihamọra rẹ̀ ṣe, o jasi iwọn ogún ọkọnrin ninu abọ iṣẹko kan ti malu meji iba tú.

15 Ibẹ̀ru si wà ninu ogun na, ni pápá, ati ninu gbogbo awọn enia na; ile ọmọ-ogun olodi, ati awọn ti iko ikogun, awọn pẹlu bẹ̀ru; ilẹ si mì: bẹ̃li o si jasi ọwáriri nlanla.

16 Awọn ọkọnrin ti nṣọ́na fun Saulu ni Gibea ti Benjamini wò; nwọn si ri ọpọlọpọ awọn enia na tuka, nwọn si npa ara wọn bi nwọn ti nlọ.

17 Saulu si wi fun awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀ pe, Njẹ ẹ kà awọn enia na ki ẹ si mọ̀ ẹniti o jade kuro ninu wa. Nwọn si kà, si kiye si i, Jonatani ati ẹniti o rù ihamọra rẹ̀ kò si si.

18 Saulu si wi fun Ahia pe, Gbe apoti Ọlọrun na wá nihinyi. Nitoripe apoti Ọlọrun wà lọdọ awọn ọmọ Israeli li akokò na.

19 O si ṣe, bi Saulu ti mba alufa na sọ̀rọ, ariwo ti o wà ni budo awọn Filistini si npọ̀ si i: Saulu si wi fun alufa na pe, dawọ́ duro.

20 Saulu ati gbogbo enia ti o wà lọdọ rẹ̀

Digitized by Google

ko ara wọn jọ pọ̀, nwọn wá si oju ija: kiye
si i, ida olukuluku si wà li ara ọmọnikeji
rẹ̀, rudurudu na si pọ̀ gidigidi.
21 Pẹlupẹlu awọn Heberu ti o wà lọdọ
awọn Filistini nigba atijọ, ti o si ti goke
ba wọn lọ si budo lati ilu ti o wà yikakiri,
awọn na pẹlu si yipada lati dapọ̀ mọ awọn
Israeli ti o wà lọdọ Saulu ati Jonatani.
22 Bẽ gẹgẹ nigbati gbogbo awọn ọkọnrin
Israeli ti o ti pa ara wọn mọ ninu okenla
Efraimu gbọ́ pe awọn Filistini sa, awọn na
pẹlu tẹle wọn lẹhin kikan ni ijà na.
23 Bẽli Oluwa si gbà Israeli là lọjọ na:
ija na si rekọja si Bet-afeni.
24 Awọn ọkọnrin Israeli si ri ipọnju
gidigidi ni ijọ na: nitoriti Saulu fi awọn
enia na bu pe, Ifibu ni fun ẹniti o jẹ onjẹ
titi di alẹ titi emi o si fi gbẹsan lara awọn
ọta mi. Bẽni kò si ẹnikan ninu awọn enia
na ti o fi ẹnu kan onjẹ.
25 Gbogbo awọn ara ilẹ na si de igbo
kan, oyin si wà lori ilẹ na.
26 Nigbati awọn enia si wọ inu igbo na,
si kiye si i oyin na nkán; ṣugbọn kò si
ẹnikan ti o mu ọwọ́ rẹ̀ re ẹnu rẹ̀; nitoripe
awọn enia bẹ̀ru ifibu na.
27 Ṣugbọn Jonatani kò gbọ́ nigbati baba
rẹ̀ fi ifibu kilọ fun awọn enia na: o si tẹ
ori ọpa ti mbẹ lọwọ rẹ̀ bọ afara oyin na, o
si fi i si ẹnu rẹ̀, oju rẹ̀ mejeji si walẹ.
28 Nigbana li ọkan ninu awọn enia na
dahùn wipe, Baba rẹ ti fi ifibu kilọ fun
awọn enia na, pe, Ifibu li ọkọnrin na ti o jẹ
onjẹ li oni. Arẹ̀ si mu awọn enia na.
29 Nigbana ni Jonatani wipe, baba mi
yọ ilu li ẹnu, sa wo bi oju mi ti walẹ, nito-
ri ti emi tọ diẹ wò ninu oyin yi.
30 A! nitotọ, ibaṣepe awọn enia na ti
jẹ ninu ikogun awọn ọta wọn ti nwọn ri,
pipa awọn Filistini iba ti pọ to?
31 Nwọn pa ninu awọn Filistini li ọjọ
na, lati Mikmaṣi de Aijaloni: o si rẹ̀ awọn
enia na gidigidi.
32 Awọn enia sare si ikogun na, nwọn
si mu agutan, ati malu, ati ọmọmalu, nwọn
si pa wọn sori ilẹ: awọn enia na si jẹ wọn
t'ẹjẹ t'ẹjẹ.
33 Nigbana ni nwọn wi fun Saulu pe,
Kiye si i, awọn enia na dẹ̀ṣẹ si Oluwa, li
eyi ti nwọn jẹ ẹjẹ. On si wipe, Ẹnyin ṣẹ̀
kọja: yi okuta nla fun mi wá loni.
34 Saulu si wipe, Ẹ tú ara nyin ka sarin
awọn enia na ki ẹ si wi fun wọn pe, Ki
olukuluku ọkọnrin mu malu tirẹ̀ tọ̀ mi wá,
ati olukuluku ọkọnrin agutan rẹ̀, ki ẹ si
pa wọn nihin, ki ẹ si jẹ, ki ẹ má si ṣẹ̀ si
Oluwa, ni jijẹ ẹjẹ. Gbogbo enia olukuluku
ọkọnrin mu malu rẹ̀ wá li alẹ na, nwọn si
pa wọn ni ibẹ̀.
35 Saulu si tẹ pẹpẹ kan fun Oluwa;
eyi ni pẹpẹ ti o kọ ṣe fun Oluwa.
36 Saulu wipe, Ẹ jẹ ki a sọkalẹ tọ̀ awọn
Filistini lọ li oru, ki a ba wọn ja titi di
imọlẹ owurọ̀, ẹ má jẹ ki a fi ọkọnrin kan
silẹ ninu wọn. Nwọn si wipe, Ṣe gbogbo
eyi ti o tọ loju rẹ. Nigbana ni alufa si
wipe, Ẹ jẹ ki a sunmọ ihinyi si Ọlọrun.
37 Saulu si bere lọdọ Ọlọrun pe, ki
emi ki o sọkalẹ tọ̀ awọn Filistini lọ bi?
Iwọ o fi wọn le Israeli lọwọ́ bi? ṣugbọn kò
da a lohùn li ọjọ na.
38 Saulu si wipe Mu gbogbo awọn àgba
enia sunmọ ihinyi, ki ẹ mọ̀, ki ẹ si ri ibiti
ẹ̀ṣẹ yi wà loni.
39 Nitoripe gẹgẹ bi Oluwa ti wà ti o ti
gbà Israeli là, bi o tilẹ ṣepe a ri i lara Jona-
tani ọmọ mi, nitõtọ yio kú. Ṣugbọn ninu
gbogbo enia na, kò si ẹniti o da a lohùn.
40 Saulu si wi fun gbogbo awọn Israeli
pe, Ẹnyin lọ si apakan, emi ati Jonatani
ọmọ mi a si lọ si apakan. Gbogbo enia si
wi fun Saulu pe, Ṣe eyi ti o tọ li oju rẹ.
41 Saulu si wi fun Oluwa Ọlọrun Israeli
pe, fun mi ni ibò ti o pé. A si mu Saulu
ati Jonatani: ṣugbọn awọn enia na yeje.
42 Saulu si wipe, Di ibò ti emi ati ti
Jonatani ọmọ mi. Ibò na si mu Jonatani.
43 Saulu si wi fun Jonatani pe, Sọ nkan
ti o ṣe fun mi. Jonatani si sọ fun u, o si
wipe, Nitõtọ mo fi ori ọ̀pá ti mbẹ li ọwọ́
mi tọ́ oyin diẹ wò, wõ emi mura ati kú.
44 Saulu si wipe, ki Ọlọrun ki o ṣe bẽ
ati ju bẽ lọ pẹlu: nitoripe iwọ Jonatani
yio sa kú dandan.
45 Awọn enia si wi fun Saulu pe, Jona-
tani yio kú, ti o ṣe igbala nla yi ni Israeli?
ki a má ri i; bi Oluwa ti wà, ọkan ninu
irun ori rẹ̀ kì yio bọ́ silẹ; nitoripe o ba
Ọlọrun ṣiṣẹ pọ̀ loni. Bẽli awọn enia si
gbà Jonatani silẹ, kò si kú.
46 Saulu si ṣiwọ ati ma lepa awọn Filis-
tini: awọn Filistini si lọ si ilu wọn.
47 Saulu si jọba lori Israeli; o si bá
gbogbo awọn ọta rẹ̀ jà yika, eyini ni Moabu
ati awọn ọmọ Ammoni, ati Edomu, ati
awọn ọba Soba ati awọn Filistini: ati ibi-
kibi ti o yi si, a bà wọn ninu jẹ.
48 O si ko ogun jọ, o si kọlu awọn
Amaleki, o si gbà Israeli silẹ lọwọ awọn ti
o nkó wọn.
49 Awọn ọmọ Saulu si ni Jonatani, ati
Iṣui, ati Malkiṣua; ati orukọ ọmọbirin rẹ̀

Digitized by Google

mejeji si ni wọnyi; orukọ akọbi ni Merabu, ati orukọ aburo ni Mikali:
50 Ati orukọ aya Saulu ni Ahinoamu, ọmọbirin Ahimaasi, ati orukọ olori ogun rẹ̀ ni Abneri ọmọ Neri arakọnrin baba Saulu.
51 Kiṣi si ni baba Saulu; ati Neri ni baba Abneri ọmọ Abieli.
52 Ogun na si le si awọn Filistini ni gbogbo ọjọ Saulu: bi Saulu ba ri ẹnikan ti o li agbara, tabi akikanju ọkọnrin, a mu u sọdọ rẹ̀.

## ORI 15.

SAMUELI ti wi fun Saulu pe, Oluwa rán mi lati fi ami ororo yàn ọ li ọba, lori enia rẹ̀, lori Israeli, nitorina nisisiyi iwọ fetisi ohùn ọ̀rọ Oluwa.
2 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, emi ranti eyi ti Amaleki ti ṣe si Israeli, bi o ti lumọ dè e li ọ̀na, nigbati on goke ti Egipti jade wá.
3 Lọ nisisiyi ki o si kọlu Amaleki, ki o si pa gbogbo nkan wọn li aparun, má si ṣe da wọn si; ṣugbọn pa ati ọkọnrin ati obirin wọn, ọmọ kekere ati awọn ti o wà li ẹnu ọmu, malu ati agutan, ibakasiẹ ati kẹtẹkẹtẹ.
4 Saulu si ko awọn enia na jọ pọ̀ o si ka iye wọn ni Telaimu, nwọn si jẹ ogun ọkẹ awọn ọkọnrin ogun ẹlẹsẹ, pẹlu ẹgbarun awọn ọkọnrin Juda.
5 Saulu si wá si ilu-nla kan ti awọn ara Amaleki, a si ba dè wọn li afonifoji kan.
6 Saulu si wi fun awọn Keniti pe, Ẹ lọ, yẹra kuro larin awọn ara Amaleki, ki emi ki o má ba run nyin pẹlu wọn: nitoripe ẹnyin ṣe ore fun gbogbo awọn ọmọ Israeli nigbati nwọn goke ti Egipti wá. Awọn Keniti yẹra kuro larin Amaleki.
7 Saulu si kọlu Amaleki lati Hafila titi iwọ o fi de Ṣuri, ti o wà li apa keji Egipti.
8 O si mu Agagi Ọba Amaleki lãye, o si fi oju ida run gbogbo awọn enia na.
9 Ṣugbọn Saulu ati awọn enia na da Agagi si, ati eyi ti o dara julọ ninu agutan ati ninu malu, ati ohun eyi ti o dara tobẽ ninu wọn, ati ọdọ-agutan abọpa, ati gbogbo nkan ti o dara; nwọn kò si fẹ pa wọn run: ṣugbọn gbogbo nkan ti kò dara ti kò si nilari ni nwọn parun patapata.
10 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ Samueli wá wipe.
11 Emi kãnu gidigidi ti emi fi Saulu jọba: nitoriti o ti yipada lẹhin mi, kò si mu ọ̀rọ mi ṣẹ. O si ba Samueli ninu jẹ gidigidi; on si kepe Oluwa ni gbogbo oru na.
12 Nigbati Samueli si dide ni kutukutu owurọ̀ lati pade Saulu, nwọn si sọ fun Samueli pe, Saulu ti wá si Karmeli, sa wõ, on kọ ibi kan fun ara rẹ̀ o si ti lọ, o si kọja siwaju, o si sọkalẹ lọ si Gilgali.
13 Samueli si tọ Saulu wá: Saulu si wi fun u pe, Alabukún ni ọ lati ọdọ Oluwa wá: emi ti ṣe eyi ti Oluwa ran mi.
14 Samueli si wipe, njẹ ewo ni igbe agutan ti emi ngbọ́ li eti mi, ati igbe malu ti emi ngbọ́?
15 Saulu si wi fun u pe, eyi ti nwọn mu ti Amaleki wá ni, ti awọn enia dasi ninu awọn agutan ton ti malu ti o dara julọ'lati fi rubọ si Oluwa Ọlọrun rẹ; a si pa eyi ti o kù run.
16 Samueli si wi fun Saulu pe, Duro, emi o si sọ eyi ti Oluwa wi fun mi li alẹ yi. On si wi fun u pe, Ma wi.
17 Samueli si wipe, Iwọ kò ha kere loju ara rẹ nigbati a fi ọ ṣe olori ẹya Israeli, ti Oluwa fi ami ororo sọ ọ di ọba Israeli?
18 Oluwa si ran ọ ni iṣẹ, o si wipe, Lọ, ki o si pa awọn ẹlẹṣẹ ara Amaleki run, ki o si ba wọn jà titi o fi run wọn.
19 Eha si ti ṣe ti iwọ kò fi gbọ́ ohùn Oluwa, ṣugbọn iwọ si sare si ikogun, ti iwọ si ṣe buburu li oju Oluwa.
20 Saulu si wi fun Samueli pe, Nitotọ, emi gbà ohùn Oluwa gbọ́, emi si ti lọ li ọ̀na ti Oluwa ran mi, emi si ti mu Agagi ọba Amaleki wá, emi si ti pa ara Amaleki run.
21 Ṣugbọn awọn enia na ti mu ninu ikogun, agutan ati malu, pàtaki nkan wọnni ti a ba pa run, lati fi rubọ si Oluwa Ọlọrun rẹ ni Gilgali.
22 Samueli si wipe, Oluwa ha ni inudidun si ọrẹ sisun ati ẹbọ bi pe ki a gbà ohùn Oluwa gbọ́? kiye si i, igbọran sàn jù ẹbọ lọ, ifetisi lẹ̀ si sàn jù ọra àgbo lọ.
23 Nitoripe iṣọtẹ dabi ẹ̀ṣẹ afọṣẹ, ati agìdi gẹgẹ bi ìwa buburu ati ibọriṣa. Nitoripe iwọ kọ̀ ọ̀rọ Oluwa, on si kọ̀ ọ li ọba.
24 Saulu si wi fun Samueli pe, Emi ti ṣẹ̀: nitoriti emi ti re ofin Oluwa kọja, ati ọ̀rọ rẹ̀: nitori emi bẹ̀ru awọn enia, emi si gbà ohùn wọn gbọ́.
25 Ṣugbọn nisisiyi, emi bẹ̀ ọ, dari ẹ̀ṣẹ mi jì mi, ki o si yipada pẹlu mi, ki emi ki o le tẹriba niwaju Oluwa.
26 Samueli si wi fun Saulu pe, emi kì yio tun yipada pẹlu rẹ mọ nitoriti iwọ ti kọ̀ ọ̀rọ Oluwa, Oluwa si ti kọ̀ iwọ lati ma jẹ ọba lori Israeli.

Digitized by Google

27 Bi Samueli si ti yipada lati lọ, o si
di ẹ̀wu ileke rẹ̀ mu, o si faya mọ̃ lọwọ́.
28 Samueli si wi fun u pe, Oluwa fa
ijọba Israeli ya kuro lọwọ rẹ lọni, o si fi
fun aladugbo rẹ kan, ti o sàn ju ọ lọ.
29 Agbara Israeli kì yio ṣeke bẽni kì yio
si ronupiwada: nitoripe ki iṣe ẹda ti yio fi
ronupiwada.
30 O si wipe, emi ti dẹ̀ṣẹ: ṣugbọn bu
ọlá fun mi, jọwọ, niwaju awọn agbãgbà
enia mi, ati niwaju Israeli, ki o si tun
yipada pẹlu mi, ki emi ki o le tẹriba
niwaju Oluwa Ọlọrun rẹ.
31 Samueli si yipada, o si tẹle Saulu;
Saulu si tẹriba niwaju Oluwa.
32 Samueli sì wipe, Mu Agagi ọba awọn
ara Amaleki na tọ̀ mi wá nihinyi. Agagi
si tọ̀ ọ wá ni idaraya. Agagi si wipe,
Nitotọ ikoro ikú ti kọja.
33 Samueli si wipe, Gẹgẹ bi idà rẹ ti sọ
awọn obirin di alaili ọmọ, bẽ gẹgẹ ni iya rẹ
yio si di alaili ọmọ larin obirin. Samueli
si pa Agagi niwaju Oluwa ni Gilgali.
34 Samueli si lọ si Rama; Saulu si goke
lọ si ile rẹ̀ ni Gibea ti Saulu.
35 Samueli kò si tun pada wá mọ lati
wo Saulu titi o fi di ọjọ ikú rẹ̀: ṣugbọn
Samueli kãnu fun Saulu: o si dùn Oluwa
nitori on fi Saulu jẹ ọba lori Israeli.

ORI 16.

OLUWA si wi fun Samueli pe, Yio ti pẹ
to ti iwọ o fi ma kãnu Saulu, nigbati
o jẹ pe, mo ti kọ̀ ọ lati ma jọba lori Israeli?
Fi ororo kún iwo rẹ, ki o si lọ, emi o rán ọ
tọ̀ Jesse ara Betlehemu: nitoriti emi ti ri
ọba kan fun ara mi ninu awọn ọmọ rẹ̀.
2 Samueli si wi pe, Emi o ti ṣe lọ? bi
Saulu ba gbọ́ yio si pa mi. Oluwa si wi
fun u pe, mu ọdọ-malu kan li ọwọ́ rẹ, ki o
si wipe, Emi wá rubọ si Oluwa.
3 Ki o si pe Jesse si ibi ẹbọ na, emi o si
fi ohun ti iwọ o ṣe hàn ọ: iwọ o si ta ororo
si ori ẹniti emi o da orukọ fun ọ.
4 Samueli si ṣe eyi ti Oluwa wi fun u, o
si wá si Betlehemu. Awọn agbà ilu na si
bẹ̀ru nitori wiwá rẹ̀, nwọn si wipe, Alafia
ki iwọ ba wá bi?
5 On si dahùn wipe, Alafia ni: emi wá
rubọ si Oluwa; ẹ ṣe ara nyin ni mimọ́, ki
ẹ si wá pẹlu mi si ibi ẹbọ na. On si yà
Jesse sí mimọ́, ati awọn ọmọ rẹ̀, o si pe wọn
si ẹbọ na.
6 O si ṣe nigbati nwọn de, o ri Eliabu,
o si wipe, nitotọ ẹni-àmi-ororo Oluwa mbẹ
niwaju rẹ̀.
7 Ṣugbọn Oluwa wi fun Samueli pe, máṣe
wo oju rẹ̀, tabi giga rẹ̀; nitoripe emi kọ̀ ọ:
nitoriti Oluwa kì iwò bi enia nti nwò; enia
a ma wo oju, Oluwa a ma wo ọkàn.
8 Jesse si pe Abinadabu, o si mu ki o
kọja niwaju Samueli. On si wipe, Oluwa
kò si yan eleyi.
9 Jesse si mu ki Ṣamma ki o kọja. On
si wipe, Oluwa kò si yàn eyi.
10 Jesse si tun mu ki awọn ọmọ rẹ̀
mejeje kọja niwaju Samueli. Samueli si
wi fun Jesse pe, Oluwa kò yan awọn
wọnyi.
11 Samueli si bi Jesse lere pe, gbogbo
awọn ọmọ rẹ li o wà nihin bi? on si dahun
wipe, abikẹhin wọn li o kù, sa wõ, o nṣọ
agutan. Samueli si wi fun Jesse pe, Ranṣẹ
ki o si mu u wá: nitoripe awa kì yio joko
titi on o fi de ihinyi.
12 O si ranṣẹ, o si mu u wá. On si jẹ
ẹnipupa, ti o lẹwà loju, o si dara lati ma
wò. Oluwa si wi fun u pe, Dide, ki o si fi
ororo sà a li àmi: nitoripe on na li eyi.
13 Nigbana ni Samueli si mu iwo ororo,
o si fi yà a si ọ̀tọ larin awọn arakọnrin rẹ̀;
Ẹmi Oluwa si bà le Dafidi lati ọjọ na lọ,
Samueli si dide, o si lọ si Rama.
14 Ṣugbọn Ẹmi Oluwa fi Saulu silẹ, ẹmi
buburu lati ọdọ Oluwa si nyọ ọ li ẹnu.
15 Awọn iranṣẹ Saulu si wi fun u pe,
Jọwọ, sa wõ ẹmi buburu lati ọdọ Ọlọrun
nyọ ọ li ẹnu.
16 Njẹ ki oluwa wa fi aṣẹ fun awọn
iranṣẹ rẹ̀ ti o wà niwaju rẹ̀ lati wá ọkọnrin
kan ti o mọ̀ ifi duru kọrin: yio si ṣe ni-
gbati ẹmi buburu na lati ọdọ̀ Ọlọrun wá ba
de si ọ, yio si fi ọwọ́ rẹ̀ kọrin lara dùru,
iwọ o si sàn.
17 Saulu si wi fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe,
Njẹ ẹ ba mi wá ọkọnrin kan, ti o mọ̀ iṣẹ́ orin
daju, ki ẹ si mu u tọ̀ mi wá.
18 Ọkan ninu iranṣẹ wọnni si dahùn
wipe, Wõ emi ri ọmọ Jesse kan ti Betle-
hemu ti o mọ̀ iṣẹ orin, o si jẹ ẹni ti o li
agbara gidigidi, ati ologun, ati ẹni ti o
ni ìọgbọ́n ọ̀rọ isọ, ati arẹwa, Oluwa si wà
pẹlu rẹ̀.
19 Saulu si ran iranṣẹ si Jesse wipe, ran
Dafidi ọmọ rẹ si mi, ẹniti o nṣọ agutan.
20 Jesse si mu kẹtẹkẹte, o si di ẹrù
akara le e, ati igò ọti-waini, ati ọmọ ewurẹ;
o si ran wọn nipa ọwọ Dafidi ọmọ rẹ̀ si
Saulu.
21 Dafidi si tọ Saulu lọ, o si duro niwaju
rẹ̀: on si fẹ ẹ gidigidi; Dafidi si wa di
ẹniti nrù ihamọra rẹ̀.

Digitized by Google

22 Saulu si ranṣẹ si Jesse pe, Jẹ ki Da-
fidi, emi bẹ ọ, duro niwaju mi ; nitori ti o
wù mi.
23 O si ṣe, nigbati ẹmi buburu lati ọdọ
Ọlọrun wá ba de si Saulu, Dafidi a si fi
ọwọ́ rẹ̀ kọrin lara duru : a si san fun
Saulu, ara rẹ̀ a si da ; ẹmi buburu na, a si
fi i silẹ.

ORI 17.

AWỌN Filistini si gbá ogun wọn jọ si oju
ijà, nwọn si gba ara wọn jọ si Ṣoko, ti
iṣe ti Juda, nwọn si do si Ṣoko ati Aseka,
ni Efesdammimi.
2 Saulu ati awọn enia Israeli si gbá ara
wọn jọ pọ̀, nwọn si do ni afonifoji Ela,
nwọn si té ogun de awọn Filistini.
3 Awọn Filistini si duro lori oke kan li
apa kan, Israeli si duro lori oke kan li apa
keji : afonifoji kan si wa larin wọn.
4 Akikanju kan si jade lati ibudo awọn
Filistini wá, orukọ rẹ̀ ama jẹ Goliati, ara
Gati, ẹniti giga rẹ̀ jẹ igbọnwọ mẹfa ati ibu
atẹlẹwọ kan.
5 On si ni akoro idẹ kan li ori rẹ̀, o si
wọ̀ ẹ̀wu kan ti a fi idẹ pẹlẹbẹ pẹlẹbẹ ṣe,
iwọn ẹwu na si jẹ ẹgbẹdọgbọn Ṣekeli idẹ.
6 On si ni kobita idẹ li ẹsẹ rẹ̀, ati apata
idẹ kan larin ejika rẹ̀.
7 Ọpa ọ̀kọ rẹ̀ si dabi igi awọn awunṣọ,
ati ori ọ̀kọ rẹ̀ si jẹ ẹgbẹta oṣuwọn sekeli
irin : ẹnikan ti o ru awà kan si nrin niwa-
ju rẹ̀.
8 O si duro o si kigbe si ogun Israeli, o
si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin jade lati
tẹgun ? ṣe Filistini kan li emi iṣe ? ẹnyin
si jẹ ẹrú Saulu. Ẹnyin yan ọkọnrin kan
fun ara nyin, ki ẹnyin si jẹ ki o sọkale tọ̀
mi wá.
9 Bi on ba le ba mi ja, ki o si pa mi,
nigbana li awa o di ẹrú nyin : ṣugbọn bi
emi le ṣẹgun rẹ̀, ti emi si pa a, nigbana
ni ẹnyin a si di ẹrú wa, ẹnyin o si ma
sin wa.
10 Filistini na si wipe, Emi fi ija lọ̀ ogun
Israeli li oni : fi ọkọnrin kan fun mi, ki
awa mejeji jumọ ba ara wa jà.
11 Nigbati Saulu ati gbogbo Israeli gbọ́
ọ̀rọ Filistini na, nwọn damu, ẹ̀ru nlanla si
ba wọn.
12 Dafidi si jẹ ọmọ ara Efrata na ti
Betlehemu-juda, orukọ ẹniti ijẹ Jesse ; o
si ni ọmọ mẹjọ, o si jẹ arugbo larin enia li
ọjọ Saulu.
13 Awọn mẹta ti o dàgba ninu awọn
ọmọ Jesse, si tọ Saulu lẹhin lọ si oju ijà :
orukọ awọn ọmọ mẹtẹta ti o lọ si ibi ijà si
ni Eliabu, akọbi, atẹle rẹ̀ si ni Abinadabu,
ẹkẹta si ni Ṣamma.
14 Dafidi si ni abikẹhin : awọn ẹgbọ́n
iwaju rẹ̀ mẹtẹta ntọ̀ Saulu lẹhin.
15 Ṣugbọn Dafidi lọ, o si yipada lẹhin
Saulu, lati ma tọju agutan baba rẹ̀ ni
Betlehemu.
16 Filistini na a si ma sunmọ itosi li
owurọ ati li alẹ, on si fi ara rẹ̀ han li ogoji
ọjọ.
17 Jesse si wi fun Dafidi ọmọ rẹ̀ pe,
Jọwọ, mu agbado didin yi ti efa kan, ati
iṣu akara mẹwa yi fun awọn ẹgbọn rẹ, ki o
si sure tọ awọn ẹgbọn rẹ ni ibudo ;
18 Ki o si mu warakasi mẹwa wọnyi fun
oloriogun ẹgbẹrun wọn, ki o si wo bi awọn
ẹgbọn rẹ ti nṣe, ki o si gbà nkan àmi wọn
wá.
19 Saulu, ati awọn, ati gbogbo ọkọnrin
Israeli si wà ni afonifoji Ela, nwọn mba
awọn Filistini jà.
20 Dafidi si dide ni kutukutu owurọ, o
si fi agutan wọnni le olutọju kan lọwọ, o si
mura, o si lọ, gẹgẹ bi Jesse ti fi aṣẹ fun u ;
on si de ibi yàra, ogun na si nlọ si oju ijà,
nwọn hó iho ogun.
21 Israeli ati Filistini si tẹgun, ogun si
pade ogun
22 Dafidi si fi nkan ti o nmu lọ le ọkan
ninu awọn olutọju nkan gbogbo lọwọ, o si
sare si ogun, o tọ awọn ẹgbọn rẹ̀ lọ, o si ki
wọn.
23 Bi on si ti mba wọn sọ̀rọ, sa wõ, aki-
kanju ọkọnrin na, Filistini ti Gati, ti orukọ
rẹ̀ njẹ Goliati si goke wá, lati ogun awọn
Filistini, o si sọ gẹgẹ bi ọ̀rọ ti o ti nsọ ri :
Dafidi si gbọ́.
24 Gbogbo ọkọnrin Israeli, nigbati nwọn
si ri ọkọnrin na, nwọn si sa niwaju rẹ̀, ẹ̀ru
si ba wọn gidigidi.
25 Awọn ọkọnrin Israeli si wipe, Ẹnyin
kò ri ọkọnrin yi ti o goke wá ihin ? lati pe
Israeli ni ijà li o ṣe wá : yio si ṣe pe, ẹniti
o ba pa ọkọnrin na, ọba yio si fi ọrọ̀ pipọ
fun u, yio si fun u li ọmọ rẹ̀ obirin, yio si
sọ ile baba rẹ di omnira ni Israeli.
26 Dafidi si wi fun awọn ọkọnrin ti o
duro li ọdọ rẹ̀ pe, Kili a o ṣe fun ọkọnrin
na ti o ba pa Filistini yi, ti o si mu ẹgàn
na kuro li ara Israeli ? tali alaikọla Filis-
tini yi iṣe, ti yio fi ma gan ogun Ọlọrun
alãye ?
27 Awon enia na si da a li ohùn gẹgẹ bi
ọ̀rọ yi pe, Bayi ni nwọn o ṣe fun ọkọnrin
ti o ba pa a.

Digitized by Google

28 Eliabu ẹgbọn rẹ̀ si gbọ́ nigbati on ba
awọn ọkọnrin na sọ̀rọ; Eliabu si binu si
Dafidi, o si wipe, ẽ ti ṣe ti iwọ fi sọkalẹ wá
ihinyi, tani iwọ ha fi agutan diẹ nì le lọwọ́
li aginju? emi mọ̀ igberaga rẹ, ati buburu
ọkàn rẹ; nitori lati ri ogun ni iwọ ṣe sọkalẹ
wá.
29 Dafidi si dahùn wipe, Kini mo ṣe
nisisiyi? ko ha ni idi bi?
30 On si yipada kuro lọdọ rẹ̀ si ẹlomi-
ran, o si sọ bakanna: awọn enia na si fi
esì fun u gegẹ bi ọ̀rọ iṣaju.
31 Nwọn si gbọ́ ọ̀rọ ti Dafidi sọ, nwọn
si sọ gbogbo wọn li oju Saulu: on si ranṣẹ
pè e.
32 Dafidi si wi fun Saulu pe, Ki aiya ki
o máṣe fò ẹnikẹni nitori rẹ̀; iranṣẹ rẹ yio
lọ, yio si ba Filistini yi jà.
33 Saulu si wi fun Dafidi pe, Iwọ kò le
tọ Filistini yi lọ lati ba a jà: nitoripe
ọdọmọde ni iwọ, on si jẹ jagun-jagun lati
igba ewe rẹ̀ wá.
34 Dafidi si wi fun Saulu pe, Nigbati
iranṣẹ rẹ nṣọ agutan baba rẹ̀, kiniun kan si
wá, ati amọtẹkun kan, o si gbe ọdọ agutan
kan lati inu agbo.
35 Mo si jade tọ̀ ọ, mo si lù u, mo si
gbà a kuro li ẹnu rẹ̀: nigbati o si dide si
mi, mo gbá irugbọ̀n rẹ̀ mu, mo si lù u, mo
si pa a.
36 Iranṣẹ rẹ pa ati kiniun ati amọtẹkun
na: alaikọla Filistini yi yio si dabi ọkan
ninu wọn, nitoripe on ti pe ogun Ọlọrun
alãye ni ijà.
37 Dafidi si wipe, Oluwa ti o gbà mi
lọwọ́ kiniun ati lọwọ́ amọtẹkun, on na ni
yio gbà mi lọwọ́ Filistini yi. Saulu si wi
fun Dafidi pe, Lọ, Oluwa yio si pẹlu rẹ.
38 Saulu si fi gbogbo ihamọra ogun rẹ̀
wọ̀ Dafidi, o si fi ibori idẹ kan bò o li ori;
o si fi ẹwu ti a fi irin adarọ pẹlẹbẹ-pẹlẹbẹ
ṣe wọ̀ ọ.
39 Dafidi si di ida rẹ̀ mọ ihamọra rẹ̀, on
si gbiyanju lati lọ, on kò sa iti dan a wò.
Dafidi si wi fun Saulu pe, Emi kò le ru
wọnyi lọ, nitoripe emi kò idan a wò. Da-
fidi si tu wọn kuro li ara rẹ̀.
40 On si mu ọpá rẹ̀ li ọwọ́ rẹ̀, o si ṣà
okuta marun ti o jọlọ̀ ninu odò, o si fi wọn
sinu apò oluṣọ agutan ti o ni, ani sinu asù-
wọn: kànakana rẹ̀ ti wà li ọwọ́ rẹ̀; o si
sunmọ Filistini na.
41 Filistini na si mbọ̀, o si nsunmọ
Dafidi; ati ọkọnrin ti o rù awà rẹ̀ si mbọ̀
niwaju rẹ̀.
42 Nigbati Filistini na si wò, ti o si ri
Dafidi, o ṣata rẹ̀: nitoripe ọdọmọdekọnrin
ni iṣe, o pọn, o si ṣe arẹwa enia.
43 Filistini na si wi fun Dafidi pe, Emi
ha nṣe aja bi, ti iwọ fi mu ọpá tọ̀ mi wá?
Filistini na si fi Dafidi ré nipa awọn ọlọrun
rẹ̀.
44 Filistini na si wi fun Dafidi pe, Mã
bọ̀; emi o si fi ẹran ara rẹ fun awọn ẹiyẹ
oju ọrun, ati fun awọn ẹranko papá.
45 Dafidi si wi fun Filistini na pe, Iwọ
mu idà, ati ọ̀kọ, ati awà tọ̀ mi wá; ṣugbọn
emi tọ̀ ọ wá li orukọ Oluwa awọn ọmọ-
ogun, Ọlọrun ogun Israeli ti iwọ ti gàn.
46 Loni yi li Oluwa yio fi iwọ le mi
lọwọ́, emi o pa ọ, emi o si ke ori rẹ kuro li
ara rẹ; emi o si fi okú ogun Filistini fun
ẹiyẹ oju ọrun loni yi, ati fun ẹranko igbẹ;
gbogbo aiye yio si mọ̀ pe, Ọlọrun wà fun
Israeli.
47 Gbogbo ijọ enia yio si mọ̀ daju pe,
Oluwa kò fi ida on ọ̀kọ gbà ni la: nitori-
pe ogun na ti Oluwa ni, yio si fi ọ le wa
lọwọ́.
48 O si ṣe, nigbati Filistini na dide, ti o
nrìn, ti o si nsunmọ tosí lati pade Dafidi,
Dafidi si yara, o si sure si ogun lati pade
Filistini na.
49 Dafidi si fi ọwọ́ rẹ̀ si inu apò, o si mu
okuta kan lati ibẹ̀ wá, o si fì i, o si lù Filis-
tini na niwaju, okuta na si wọ inu agbari
rẹ̀ lọ, o si ṣubu dojubọlẹ.
50 Bẹ̃ni Dafidi si fi kànakàna on okuta
ṣẹgun Filistini na, o si bori Filistini na, o
si pa a; ṣugbọn idà ko si lọwọ Dafidi.
51 Dafidi si sure, o si duro lori Filistini
na, o si mu ida rẹ̀, o si fà a yọ ninu akọ̀ rẹ̀,
o si pa a, o si fi idà na bẹ́ ẹ li ori. Nigba-
ti awọn Filistini si ri pe akikanju wọn kú,
nwọn si sa.
52 Awọn ọkọnrin Israeli ati ti Juda si
dide, nwọn si ho yè, nwọn si nle awọn Fi-
listini lọ, titi iwọ o fi de afonifoji kan, ati
si ojubode Ekronu. Awọn ti o gbọgbẹ
ninu awọn Filistini si ṣubu lulẹ li ọ̀na
Ṣaaraimu, ati titi de Gati, ati Ekronu.
53 Awọn ọmọ Israeli si pada lati ma
lepa awọn Filistini, nwọn si ba budo wọn
jẹ.
54 Dafidi si gbe ori Filistini na, o si mu
u wá si Jerusalemu; ṣugbọn o fi ihamọra
rẹ̀ si inu agọ rẹ̀.
55 Nigbati Saulu si ri Dafidi ti nlọ pade
Filistini na, o si bi Abneri oloriogun pe,
Abneri, ọmọ tani ọmọde yi iṣe? Abneri
si dahun pe, bi ọkàn rẹ ti wà lãye, ọba,
emi kò mọ̀.

Digitized by Google

56 Ọba si wipe, Iwọ bere ọmọ tali ọmọde
na iṣe ?
57 Bi Dafidi si ti ti ibi ti o gbe pa Filis-
tini na bọ̀, Abneri si mu u wá siwaju
Saulu, ti on ti ori Filistini na lọwọ rẹ̀.
58 Saulu si bi i lere pe, Ọmọ tani iwọ
ọmọde yi iṣe ? Dafidi si da a li ohùn pe,
Emi li ọmọ Jesse iranṣẹ rẹ ara Betlehemu.

ORI 18.

OSI ṣe, nigbati o ba Saulu sọ̀rọ tan, ọkàn
Jonatani si fà mọ ọkàn Dafidi, Jona-
tani si fẹ ẹ bi ontikararẹ̀.
2 Saulu si mu u sọdọ lọjọ na, ko si jẹ ki
o lọ sọdọ baba rẹ̀ mọ.
3 Jonatani on Dafidi si ba ara wọn
mulẹ ; nitoripe o fẹ ẹ gẹgẹ bi o ti fẹ ọkàn
ara rẹ̀.
4 Jonatani si bọ aṣọ ileke ti o wà li ara
rẹ̀ o si fi i fun Dafidi, ati togo rẹ̀, titi de
idà rẹ̀, ọrun rẹ̀, ati amure rẹ̀.
5 Dafidi a si ma lọ si ibikibi ti Saulu
rán a, a ma huwa ọlọgbọ́n : Saulu si fi i jẹ
olori ogun, o si dara loju gbogbo awọn
enia, ati pẹlupẹlu loju awọn iranṣẹ Saulu.
6 O si ṣe, bi nwọn ti de, nigbati Dafidi
ti ibi ti o gbe pa Filistini na bọ̀, awọn
obirin si ti gbogbo ilu Israeli jade wá,
nwọn nkọrin nwọn si njo lati wá ipade
Saulu ọba, ti awọn ti ilù, ati ayọ̀, ati duru.
7 Awọn obirin si ndá, nwọn si ngbe orin
bi nwọn ti nṣire, nwọn si nwipe, Saulu pa
ẹgbẹgbẹrun tirẹ̀, Dafidi si pa ẹgbẹgbarun tirẹ̀.
8 Saulu si binu gidigidi, ọ̀rọ na si buru
loju rẹ̀ o si wipe, Nwọn fi ẹgbẹgbarun fun
Dafidi, nwọ́n si fi ẹgbẹgbẹrun fun mi, kili
o si kù fun u bikoṣe ijọba.
9 Saulu si nfi oju ilara wo Dafidi lati
ọjọ na lọ.
10 O si ṣe ni ijọ keji, ti ẹmi buburu lati
ọdọ Ọlọrun wá si ba le Saulu, on si sọtẹlẹ
li arin ile ; Dafidi si fi ọwọ́ rẹ̀ ṣire lara
duru bi igba atẹhinwa ; ẹṣín kan mbẹ lọwọ
Saulu.
11 Saulu si sọ ẹṣín ti o wà lọwọ rẹ̀ na ; o
si wipe, Emi o pa Dafidi li apa mọ́ ogiri.
Dafidi si yẹra kuro niwaju rẹ lẹmeji.
12 Saulu si bẹ̀ru Dafidi, nitoripe Oluwa
wà pẹlu rẹ̀, ṣugbọn Oluwa kọ̀ Saulu.
13 Nitorina Saulu si mu u kuro lọdọ rẹ̀,
o si fi i jẹ olori ogun ẹgbẹrun kan, o si nlọ,
o si mbọ̀ niwaju awọn enia na.
14 Dafidi si ṣe ọlọgbọ́n ni gbogbo iṣe rẹ̀ ;
Oluwa si wà pẹlu rẹ̀.
15 Nigbati Saulu ri pe, o nhuwa ọgbọ́n
gidigidi, o si mbẹ̀ru rẹ̀.
16 Gbogbo Israeli ati Juda si fẹ Dafidi,
nitoripe a ma lọ a si ma bọ̀ niwaju wọn.
17 Saulu si wi fun Dafidi pe, Wo Mera-
bu ọmọbirin mi, eyi agbà, on li emi o fi
fun ọ li aya : ṣugbọn ki iwọ ki o ṣe alagba-
ra fun mi, ki o si ma ja ija Oluwa. Nito-
riti Saulu ti wi bayi pe, Màṣe jẹ ki ọwọ́ mi
ki o wà li ara rẹ̀ ; ṣugbọn jẹ ki ọwọ́ awọn
Filistini ki o wà li ara rẹ̀.
18 Dafidi si wi fun Saulu pe, Tali emi,
ati ki li ẹmi mi, tabi idile baba mi ni
Israeli, ti emi o fi wa di ana ọba.
19 O si ṣe, li akoko ti a ba fi Merabu
ọmọbirin Saulu fun Dafidi, li a si fi i fun
Adrieli ara Meholati li aya.
20 Mikali ọmọbirin Saulu si fẹran Dafi-
di, nwọn si wi fun Saulu : nkan na si tọ li
oju rẹ̀.
21 Saulu si wipe, Emi o fi i fun u, yio
si jẹ idẹkùn fun u, ọwọ́ awọn Filistini yio
si wà li ara rẹ̀. Saulu si wi fun Dafidi pe,
Iwọ o wà di ana mi loni, ninu mejeji.
22 Saulu si paṣẹ fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe,
Ẹ lọ ba Dafidi sọ̀rọ kẹlẹkẹlẹ pe, Kiyesi i,
inu ọba dùn si ọ jọjọ, ati gbogbo awọn
iranṣẹ rẹ̀ li o si fẹ ọ, njẹ nitorina jẹ ana
ọba.
23 Awọn iranṣẹ Saulu si sọ̀rọ wọnni li
eti Dafidi. Dafidi si wipe, O ha ṣe nkan
ti o fẹrẹ loju nyin lati jẹ ana ọba ? Talaka
li emi ati ẹni ti a kò kà si.
24 Awọn iranṣẹ Saulu si wa irò fun u,
pe, Ọrọ bayi ni Dafidi sọ.
25 Saulu si wipe, Bayi li ẹnyin o sọ fun
Dafidi, ọba kò sa fẹ ohun-ana kan bikoṣe
ọgọrun ẹfa abẹ Filistini, ati lati gbẹsan
lara awọn ọta ọba ; ṣugbọn Saulu rò ikú
Dafidi lati ọwọ́ awọn Filistini wá.
26 Nigbati awọn iranṣẹ rẹ̀ si sọ̀rọ wọnyi
fun Dafidi, ohun na si dara li oju Dafidi
lati di ana ọba : ọjọ kò si iti pe.
27 Dafidi si dide, o lọ, on ati awọn
ọmọkọnrin rẹ̀, o si pa igba ọmọkọnrin ninu
awọn Filistini ; Dafidi si mu ẹfa abẹ wọn
wá, nwọn si kà wọn pe fun ọba, ki on ki
o le jẹ ana ọba. Saulu si fi Mikali ọmọ rẹ̀
obirin fun u li aya.
28 Saulu si ri o si mọ̀ pe, Oluwa wà
pẹlu Dafidi, Mikali ọmọbirin Saulu si fẹ ẹ.
29 Saulu si bẹ̀ru Dafidi siwaju ati siwa-
ju : Saulu si wa di ọtá Dafidi titi.
30 Awọn ọmọ-alade Filistini si jade lọ :
o si ṣe, lẹhin igbati nwọn lọ, Dafidi si
huwa ọlọgbọ́n ju gbogbo awọn iranṣẹ Saulu
lọ ; orukọ rẹ̀ si ni iyìn jọjọ.

Digitized by Google

## ORI 19.

SAULU si sọ fun Jonatani ọmọ rẹ̀, ati
fun gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀, pe, ki
nwọn ki o pa Dafidi.
2 Ṣugbọn Jonatani ọmọ Saulu fẹ́ràn
Dafidi pupọ: Jonatani si sọ fun Dafidi pe,
Saulu baba mi nwá ọ̀na ati pa ọ, njẹ, mo
bẹ̀ ọ, kiyesi ara rẹ titi di owurọ, ki o si joko
nibi ikọ̀kọ, ki o si sa pamọ.
3 Emi o si jade lọ, emi o si duro ti baba
mi li oko na nibiti iwọ gbe wà, emi o si ba
baba mi sọ̀rọ nitori rẹ; eyiti emi ba si ri,
emi o sọ fun ọ.
4 Jonatani si sọ̀rọ Dafidi ni rere fun
Saulu baba rẹ̀, o si wi fun u pe, Ki a máṣe
jẹ ki ọba ki o ṣẹ̀ si iranṣẹ rẹ̀, si Dafidi; ni-
tori kò ṣẹ̀ ọ, ati nitoripe iṣẹ rẹ̀ dara gidi-
gidi fun ọ.
5 Nitoriti o mu ẹmi rẹ̀ li lọwọ́ rẹ̀, o si pa
Filistini na, Oluwa si ṣiṣẹ igbala nla fun
gbogbo Israeli: iwọ ri i, o si yọ̀: njẹ, ni-
tori kini iwọ o ṣe dẹṣẹ̀ si ẹjẹ alaiṣẹ, ti iwọ o
fi pa Dafidi laiṣẹ?
6 Saulu si gbọ́ ohùn Jonatani: Saulu si
bura pe, Bi Oluwa ti wà lãye a ki yio pa a.
7 Jonatani si pe Dafidi, Jonatani si ro
gbogbo ọ̀ràn na fun u. Jonatani si mu
Dafidi tọ Saulu wá, on si wà niwaju rẹ̀, bi
igbà atijọ.
8 Ogun si tun wà sibẹ, Dafidi si jade lọ,
o si ba awọn Filistini jà, o si pa wọn pupọ;
nwọn si sa niwaju rẹ̀.
9 Ẹmi buburu lati ọdọ Oluwa wá si bà le
Saulu, o si joko ni ile rẹ̀ ton ti ẹṣín rẹ̀ li
lọwọ rẹ̀: Dafidi a si ma fi ọwọ́ rẹ̀ kọrin lara
duru.
10 Saulu ti nwá ọ̀na lati fi ẹṣín na gún
Dafidi mọ ogiri: ṣugbọn on si yẹra kuro
niwaju Saulu: o si sọ ẹṣín na wọnu ogiri:
Dafidi si sa, o si fi ara pamọ li oru na.
11 Saulu si rán onṣẹ si ile Dafidi, lati
ma ṣọ ọ ati lati pa a li owurọ: Mikali aya
Dafidi si wi fun u pe, Bi iwọ kò ba gbà
ẹmi rẹ là li alẹ yi, li ọla li a o pa ọ.
12 Mikali si sọ Dafidi kalẹ lati oju ferese
kan wá; on si lọ, o sa, o si fi ara rẹ̀ pamọ.
13 Mikali si mu ere, o si tẹ́ ẹ sori akete,
o si fi timtim onirun ewurẹ sibẹ fun irọri
rẹ̀, o si fi aṣọ bò o.
14 Nigbati Saulu si ran onṣẹ lati mu
Dafidi, on si wi fun wọn pe, Kò sàn.
15 Saulu si tun ran awọn onṣẹ na lọ iwo
Dafidi, o wi pe, Gbe e goke tọ̀ mi wá ti-
akete ti-akete ki emi ki o pa a.
16 Nigbati awọn onṣẹ na de, sa wõ, ere
li o si wà lori akete, ati timtim onirun
ewurẹ fun irọri rẹ̀.
17 Saulu si wi fun Mikali pe, Eha ti ṣe
ti iwọ fi tàn mi jẹ bẽ, ti iwọ si fi jọwọ ọta
mi lọwọ lọ, ti on si bọ? Mikali si da Saulu
lohùn pe, On wi fun mi pe, Jẹ ki emi lọ;
ẽṣe ti emi o fi pa ọ?
18 Dafidi si sa, o si bọ, o si tọ Samueli
wá ni Rama, o si rò fun u gbogbo eyi ti
Saulu ṣe si i. On ati Samueli si lọ, nwọn
si ngbe Naoti.
19 A si wi fun Saulu pe, Wõ, Dafidi
mbẹ ni Naoti ni Rama.
20 Saulu si ran onṣẹ lati mu Dafidi:
nigbati nwọn ri ẹgbẹ awọn woli ti nsọtẹlẹ,
ati Samueli ti o duro bi olori wọn, Ẹmi
Ọlọrun si bà le awọn onṣẹ Saulu, awọn na
si nsọtẹlẹ.
21 A si ro fun Saulu, o si ran onṣẹ mi-
ran, awọn na si nsọtẹlẹ. Saulu si tun ran
onṣẹ lẹ̃kẹta, awọn na si nsọtẹlẹ.
22 On na si lọ si Rama, o si de ibi kanga
nla kan ti o wà ni Seku: o si bere, o si
wipe, Nibo ni Samueli ati Dafidi gbe wà?
ẹnikan si wipe, Wõ, nwọn mbẹ ni Naoti
ni Rama.
23 On si lọ sibẹ si Naoti ni Rama: Ẹmi
Ọlọrun si ba le on na pẹlu, o si nlọ, o si
nsọtẹle titi o fi de Naoti ni Rama.
24 On si bọ aṣọ rẹ̀ silẹ, o si sọtẹlẹ pẹlu
niwaju Samueli, o si dubulẹ nihoho ni
gbogbo ọjọ na, ati ni gbogbo oru na.
Nitorina nwọn si wipe, Saulu pẹlu ha wà
ninu awọn woli?

## ORI 20.

DAFIDI si sa kuro ni Naoti ti Rama, o
si wá, o si wi li oju Jonatani pe, Kili
emi ṣe? kini ìwa buburu mi, ati kili ẹ̀ṣẹ
mi li oju baba rẹ, ti o fi nwá ọ̀na ati pa mi.
2 On si wi fun u pe, Ki a má ri i, iwọ ki
yio kú: wõ, baba mi ki yio ṣe nkan nla
tabi kekere lai sọ ọ li eti mi, njẹ, esi ti ṣe
ti baba mi yio fi pa nkan yi mọ fun mi?
nkan na kò ri bẹ̃.
3 Dafidi si tun bura, pe, baba rẹ ti mọ̀
pe, emi ri oju rere li ọdọ rẹ; on si wipe,
Máṣe jẹ ki Jonatani ki o mọ̀ nkan yi, ki o
má ba binu: ṣugbọn nitotọ, bi Oluwa ti
wà, ati bi ọkàn rẹ si ti wà lãye, iṣisẹ̀ kan
ni mbẹ larin emi ati ikú.
4 Jonatani si wi fun Dafidi pe, Ohunko-
hun ti ọkàn rẹ ba nfẹ, wi, emi o si ṣe e
fun ọ.
5 Dafidi si wi fun Jonatani pe, Wõ, li

ọla li oṣu titun, emi kò si gbọdọ ṣe alai ba
ọba joko lati jẹun; ṣugbọn jẹ ki emi ki o
lọ, ki emi si fi ara pamọ li oko titi yio fi di
aṣalẹ ijọ kẹta.
6 Bi o ba si ṣepe baba rẹ fẹ mi kù, ki o
si wi fun u pe, Dafidi bẹ̀ mi lati sure lọ si
Betlehemu ilu rẹ̀; nitoripe ẹbọ ọdun kan
kò nibẹ fun gbogbo idile na.
7 Bi o ba wipe, O dara, alafia mbẹ fun
iranṣẹ rẹ; ṣugbọn bi o ba binu pupọ, njẹ
ki iwọ ki o mọ̀ daju pe buburu ni o nrò
ninu rẹ̀.
8 Iwọ o si ṣe ore fun iranṣẹ rẹ, nitoripe
iwọ ti mu iranṣẹ rẹ wọ inu majẹmu Oluwa
pẹlu rẹ; ṣugbọn bi ìwa buburu ba mbẹ li
ọwọ mi, iwọ tikararẹ pa mi; ẽṣe ti iwọ o
fi mu mi tọ baba rẹ lọ?
9 Jonatani si wipe, Ki eyini ki o jina si
ọ: nitoripe bi emi ba mọ̀ daju pe baba mi
npete ibi ti yio wá sori rẹ, njẹ emi le iṣe
alaisọ ọ fun ọ bi?
10 Nigbana ni Dafidi wi fun Jonatani
pe, Tani yio sọ fun mi? tabi yio ti ri bi
baba rẹ ba si fi ìjãnu da ọ lohùn.
11 Jonatani si wi fun Dafidi pe, Wá, jẹ
ki a jade lọ si pápá. Awọn mejeji si jade
lọ si pápá.
12 Jonatani si wi fun Dafidi pe, Oluwa
Ọlọrun-Israeli, nigbati mo ba si lu baba mi
li ohùn gbọ́ li ọla tabi li ọtunla, si wõ, bi
ire ba wà fun Dafidi, ti emi kò ba si ranṣẹ
si ọ, ti emi kò si sọ ọ li eti rẹ.
13 Ki Oluwa ki o ṣe bẽ ati ju bẽ lọ si
Jonatani: ṣugbọn bi o ba si ṣe pe o wu
baba mi lati ṣe buburu si ọ, emi o si sọ ọ li
eti rẹ, emi o si jẹ ki o lọ, iwọ o si lọ li ala-
fia, ki Oluwa ki o si pẹlu rẹ gẹgẹ bi o ti wà
pẹlu baba mi.
14 Ki iṣe kiki igbà ti mo wà lãye ni iwọ
o si ṣe ãnu Oluwa fun mi, ki emi ki o má
kú.
15 Ṣugbọn ki iwọ ki o máṣe mu ãnu rẹ
kuro ni ile mi lailai: ki isi ṣe igbati Oluwa
ke olukuluku ọtá Dafidi kuro lori ilẹ.
16 Bẽ ni Jonatani bá ile Dafidi da ma-
jẹmu pe, Oluwa yio si bere rẹ̀ lọwọ awọn
ọta Dafidi.
17 Jonatani si tun mu ki Dafidi ki o
bura nitoriti o sa fẹ ẹ: o si fẹ ẹ bi o ti fẹ
ẹmi ara rẹ̀.
18 Nigbana ni Jonatani wi fun Dafidi
pe, ọla li oṣu titun: a o si fẹ ọ kù, nitoriti
ipò rẹ yio ṣofo.
19 Bi iwọ ba si duro ni ijọ mẹta, nigba-
na ni iwọ o si yara sọkalẹ, iwọ o si wá si
ibiti iwọ gbe ti fi ara rẹ pamọ si nigbati iṣẹ
na wà lọwọ, iwọ o si joko ni ibi okuta
Eseli.
20 Emi o si ta ọfà mẹta si ìha ibẹ̀ na,
gẹgẹ bi ẹnipe mo ta si àmi kan.
21 Si wõ, emi o ran ọmọde-kọnrin kan
pe, Lọ, ki o si wá ọfa wọnni. Bi emi ba
tẹnu mọ ọ fun ọmọkọnrin na, pe, Wõ, ọfa
wọnni wà lẹhin rẹ, ṣà wọn wá; nigbana ni
iwọ o ma bọ̀; nitoriti alafia mbẹ fun ọ,
kò si ewu; bi Oluwa ti wà.
22 Ṣugbọn bi emi ba wi bayi fun ọmọde-
kọnrin na pe, Wõ ọfa na mbẹ niwaju rẹ;
njẹ ma ba tirẹ lọ; Oluwa li o ran ọ lọ.
23 Niti ọ̀rọ ti emi ati iwọ si ti jumọ sọ,
wõ, ki Oluwa ki o wà larin iwọ ati emi titi
lailai.
24 Bẽni Dafidi sì pa ara rẹ̀ mọ li oko;
nigbati oṣu titun si de, ọba si joko lati jẹun.
25 Ọba si joko ni ipò rẹ̀ bi igba atijọ
lori ijoko ti o gbè ogiri; Jonatani si dide,
Abneri si joko ti Saulu, ipò Dafidi si ṣofo.
26 Ṣugbọn Saulu kò sọ nkan nijọ na;
nitoriti on rò pe, Nkan ṣe e ni, on ṣe
alaimọ́ ni; nitotọ o ṣe alaimọ́ ni.
27 O si ṣe, ni ijọ keji, ti o jẹ ijọ keji oṣu,
ipò Dafidi si ṣofo; Saulu si wi fun Jona-
tani ọmọ rẹ̀ pe, Ẽṣe ti ọmọ Jesse ko fi wá
si ibi onjẹ lana ati loni?
28 Jonatani si da Saulu lohùn pe, Da-
fidi bẹ̀ mi lati lọ si Betlehemu:
29 O si wipe, Jọwọ, jẹ ki emi ki o lọ:
nitoripe idile wa li ẹbọ kan iru ni ilu na;
ẹgbọn mi si paṣẹ fun mi pe ki emi ki o má
ṣaiwà nibẹ; njẹ, bi emi ba ri oju rere gbà
lọdọ rẹ, jọwọ, jẹ ki emi lọ, ki emi ri awọn
ẹgbọn mi. Nitorina ni ko ṣe wá si ibi
onjẹ ọba.
30 Ibinu Saulu si fà ru si Jonatani, o si
wi fun u pe, Iwọ ọmọ ọlọtẹ buburu yi, ṣe
emi mọ̀ pe, iwọ ti yàn ọmọ Jesse fun itiju
rẹ, ati fun itiju ihoho iya rẹ?
31 Nitoripe ni gbogbo ọjọ ti ọmọ Jesse
wà lãye li orilẹ, iwọ ati ijọba rẹ kì yio duro.
Njẹ nisisiyi, ranṣẹ ki o si mu u fun mi wá,
nitoripe yio kú dandan.
32 Jonatani si da Saulu baba rẹ̀ lohùn, o
si wi fun u pe, nitoriti kini on o ṣe kú?
kili ohun ti o ṣe?
33 Saulu si jù ẹṣín si i lati fi pa a; Jo-
natani si wa mọ̀ pe baba on ti pinnu rẹ̀ lati
pa Dafidi.
34 Bẽni Jonatani sì fi ibinu dide kuro
ni ibi onjẹ, kò si jẹun ni ijọ keji oṣu na:
inu rẹ̀ si bajẹ gidigidi fun Dafidi, nitoripe
baba rẹ̀ doju tì i.
35 O si ṣe, li owurọ ni Jonatani jade lọ

Digitized by Google

si oko li akoko ti on ati Dafidi ti fi si, ọmọdekọnrin kan si wà pẹlu rẹ̀.

36 O si wi fun ọmọdekọnrin rẹ̀ pe, sare, ki o si wá ọfà wọnni ti emi o ta. Bi ọmọde na si ti nsare, on si tafa rekọja rẹ̀.

37 Nigbati ọmọdekọnrin na si de ibi ọfà ti Jonatani ta, Jonatani si kọ si ọmọdekọnrin na, o si wipe, ọfà na ko ha wà niwaju rẹ bi?

38 Jonatani si kọ si ọmọdekọnrin na pe, Sare, yara, máṣe duro. Ọmọdekọnrin Jonatani si ṣa ọfà wọnni, o si tọ̀ oluwa rẹ̀ wá.

39 Ọmọdekọnrin na kò si mọ̀ nkan: ṣugbọn Jonatani ati Dafidi li o mọ̀ ọ̀ran na.

40 Jonatani si fi apó ati ọrun rẹ̀ fun ọmọdekọnrin rẹ̀, o si wi fun u pe, Lọ, ki o si mu wọn lọ si ilu.

41 Bi ọmọdekọnrin na ti lọ tan, Dafidi si dide lati iha gusun, o si wolẹ, o si tẹriba lẹrinmẹta: nwọn si fi ẹnu ko ara wọn li ẹnu, nwọn si jumọ sọkun, ekini keji wọn, titi Dafidi fi bori.

42 Jonatani si wi fun Dafidi pe, Ma lọ li alafia, bi o ti jẹ pe awa mejeji ti jumọ bura li orukọ Oluwa, pe, Ki Oluwa ki o wà lãrin emi ati iwọ, lãrin iru-ọmọ mi ati lãrin iru-ọmọ rẹ lailai. On si dide, o si lọ kuro: Jonatani si lọ si ilu.

## ORI 21.

DAFIDI si wá si Nobu sọdọ Ahimeleki alufa; Ahimeleki si bẹ̀ru lati pade Dafidi, o si wi fun u pe, Eha ti ri ti o fi ṣe iwọ nikan, ati ti kò si fi si ọkọnrin kan ti o pẹlu rẹ?

2 Dafidi si wi fun Ahimeleki alufa pe, ọba paṣẹ iṣẹ kan fun mi, o si wi fun mi pe, Máṣe jẹ ki ẹnikan mọ̀ idi iṣẹ na ti mo rán ọ, ati eyi ti emi ti paṣẹ fun ọ; emi si yàn awọn iranṣẹ mi si ibi bayi.

3 Njẹ kili o wà li ọwọ́ rẹ? fun mi ni ìṣu akara marun li ọwọ́ mi, tabi ohunkohun ti a ba ri.

4 Alufa na si da Dafidi lohùn o si wipe, Kò si akara miran li ọwọ́ mi bikoṣe akara mimọ́; bi awọn ọmọkọnrin ba ti pa ara wọn mọ kuro lọdọ obirin.

5 Dafidi si da alufa na lohùn, o si wi fun u pe, Nitotọ a ti pa ara wa mọ kuro lọdọ obirin lati iwọn ijọ mẹta wá, ti emi ti jade; gbogbo nkan awọn ọmọkọnrin na li o mọ́, ati akara na si wa dabi akara miran, ye e pãpã nigbati o jẹ pe omiran wà ti a yà si mimọ́ loni ninu ohun elo na.

6 Bẹ̃ni alufa na si fi akara mimọ́ fun u; nitoriti kò si akara miran nibẹ bikoṣe akara ifihan ti a ti ko kuro niwaju Oluwa, lati fi akara gbigbona sibẹ li ọjọ ti a ko o kuro.

7 Ọkọnrin kan ninu awọn iranṣẹ Saulu si mbẹ nibẹ li ọjọ na, ti a ti da duro niwaju Oluwa; orukọ rẹ̀ si njẹ Doegi, ara Edomu olori ninu awọn darandaran Saulu.

8 Dafidi si tun wi fun Ahimeleki pe, Kò si ọ̀kọ tabi idà lọwọ rẹ nihin? nitoriti emi kò mu idà mi, bẹ̃li emi kò mu nkan ijà mi lọwọ, nitoripe iṣẹ ọba na jẹ iṣẹ ikanju.

9 Alufa na si wipe, idà Goliati ara Filistini ti iwọ pa li afonifoji Ela ni mbẹ, wõ, a fi aṣọ kan wé e lẹhin Efodu; bi iwọ o ba mu eyini, mu u; kò si si omiran nihin mọ bikoṣe ọkanna. Dafidi si wipe, Kò si eyiti o dabi rẹ̀, fun mi.

10 Dafidi si dide, o si sa ni ijọ na niwaju Saulu, o si lọ sọdọ Akiṣi, ọba Gati.

11 Awọn iranṣẹ Akiṣi si wi fun u pe, Ṣe eyiyi ni Dafidi ọba ilẹ na? nwọn kò ha ti da ti nwọn si gberin nitori rẹ̀ ni ijó, pe, Saulu pa ẹgbẹrun tirẹ̀, Dafidi si pa ẹgbãrun tirẹ̀?

12 Dafidi si pa ọ̀rọ wọnyi mọ li ọkàn rẹ̀, o si bẹ̀ru Akiṣi ọba Gati gidigidi.

13 On si pa iṣe rẹ̀ dà niwaju wọn, o si sọ ara rẹ̀ di aṣiwere li ọwọ́ wọn, o si nfi ọwọ́ rẹ̀ há ilẹkun oju ọ̀na, o si nwà itọ́ si irungbọn rẹ̀.

14 Nigbana ni Akiṣi wi fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe, Wõ, ẹnyin ri pe ọkọnrin na nhuwà aṣiwere; njẹ nitori kini ẹnyin ṣe mu u tọ̀ mi wá?

15 Mo ha ni aṣiwere fi ṣe? ti ẹnyin fi mu eyi tọ̀ mi wá lati hu iwa aṣiwere niwaju mi? eleyi yio ha wọ inu ile mi?

## ORI 22.

DAFIDI si kuro nibẹ, o si sa si iho Adullamu; nigbati awọn arakọnrin rẹ̀ ati idile baba rẹ̀ si gbọ́ ọ, nwọn si sọkalẹ tọ̀ ọ nibẹ.

2 Olukuluku ẹniti o ti wà ninu ipọnju, ati olukuluku ẹniti o ti jẹ gbesè, ati olukuluku ẹniti o wà ninu ibanujẹ, si ko ara wọn jọ sọdọ rẹ̀, on si jẹ olori wọn: awọn ti o wà lọdọ rẹ̀ si to iwọn irinwo ọmọkọnrin.

3 Dafidi si ti ibẹ̀ na lọ si Mispe ti Moabu; on si wi fun ọba Moabu pe, Jẹ ki baba ati iya mi, emi bẹ̀ ọ, wá ba ọ gbe, titi emi o fi mọ̀ ohun ti Ọlọrun yio ṣe fun mi.

4 O si mu wọn wá siwaju ọba Moabu; nwọn si ba a gbe ni gbogbo ọjọ ti Dafidi fi wà ninu ihò na.

Digitized by Google

5 Gadi woli si wi fun Dafidi pe, Máṣe
gbe inu ihò na; yẹra, ki o si lọ si ilẹ Juda.
Nigbana ni Dafidi si yẹra, o si lọ sinu igbo
Hareti.
6 Saulu si gbọ́ pe a ri Dafidi ati awọn
ọkọnrin ti o wà lọdọ rẹ̀; Saulu si ngbe ni
Gibea labẹ igi kan ni Rama; ọkọ̀ rẹ̀ si mbẹ
lọwọ rẹ̀, ati gbogbo awọn iranṣẹ rẹ si duro
tì i;
7 Nighana ni Saulu wi fun awọn iranṣẹ
rẹ̀ ti o duro tì i, pe, Njẹ, ẹ gbọ́, ẹnyin ara
Benjamini, ọmọ Jesse yio ha fun olukuluku
nyin ni oko ati ọgba ajara bi, ki o si sọ
gbogbo nyin di olori ẹgbẹgbẹrun ati olori
ọrọrun bi?
8 Ti gbogbo nyin fi dimọlù si mi, ti ko
si fi si ẹnikan ti o sọ ọ li eti mi pe, ọmọ
mi ti ba ọmọ Jesse mulẹ, bẹ̃ni kò si si ẹni-
kan ninu nyin ti o ṣanu mi, ti o si sọ ọ li
eti mi pe, ọmọ mi mu ki iranṣẹ mi dide si
mi lati ba dè mi, bi o ti ri loni?
9 Doegi ara Edomu ti a fi jẹ olori awọn
iranṣẹ Saulu, si dahun wipe, Emi ri ọmọ
Jesse, o wá si Nobu, sọdọ Ahimeleki ọmọ
Ahitubu.
10 On si bere lọdọ̀ Oluwa fun u, o si fun
u li onjẹ, o si fun n ni idà Goliati ara
Filistia.
11 Ọba si iranṣẹ pe Ahimeleki alufa,
ọmọ Ahitubu ati gbogbo idile baba rẹ̀,
awọn alufa ti o wà ni Nobu: gbogbo wọn
li o si wá sọdọ ọba.
12 Saulu si wipe, Njẹ gbọ́, iwọ ọmọ
Ahitubu. On si wipe, Emi nĩ, oluwa mi.
13 Saulu si wi fun u pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi
dimọlù si mi, iwọ ati ọmọ Jesse, ti iwọ fi
fun u li akara, ati idà, ati ti iwọ fi bere
fun u lọdọ Ọlọrun, ki on ki o le dide si mi,
lati ba dè mi, bi o ti ri loni?
14 Ahimeleki si da ọba lohun, o si wipe,
Tali oluwa rẹ̀ ti o ṣe enia re ninu gbogbo
awọn iranṣẹ rẹ bi Dafidi, ẹniti iṣe ana ọba,
ẹniti o ngbọ́ tirẹ, ti o si li ọla ni ile rẹ?
15 Oni li emi o ṣẹṣẹ ma bere li ọwọ́
Ọlọrun fun u bi? ki eyini jinà si mi: ki
ọba ki o máṣe ka nkankan si iranṣẹ rẹ̀
lọrùn, tabi si gbogbo idile baba mi: nito-
ripe iranṣẹ rẹ kò mọ̀ kan ninu gbogbo
nkan yi, diẹ tabi pupọ.
16 Ọba si wipe, Ahimeleki, kikú ni iwọ
o kú, iwọ, ati gbogbo idile baba rẹ.
17 Ọba si wi fun awọn aṣaju ti ima sare
niwaju ọba, ti o duro tì i, pe, Yipada ki ẹ
si pa awọn alufa Oluwa; nitoripe ọwọ́ wọn
wà pẹlu Dafidi, ati nitoripe, nwọn mọ̀
igbati on sa, nwọn kò si sọ ọ li eti mi.
Ṣugbọn awọn iranṣẹ ọba ko si jẹ fi ọwọ́ wọn
le awọn alufa Oluwa lati pa wọn.
18 Ọba si wi fun Doegi pe, Iwọ, yipa-
da, ki o si pa awọn alufa. Doegi ara
Edomu si yipada, o si kọlu awọn alufa, o
si pa li ọjọ na, àrunlelọgọrin enia ti nwọ
aṣọ ọgbọ̀ Efodu.
19 O si fi oju ida pa ara Nobu, ilu awọn
alufa na ati ọkọnrin ati obirin, ọmọ wẹrẹ,
ati awọn ti o wà li ẹnu ọmu, ati malu, ati
kẹtẹkẹtẹ, ati agutan.
20 Ọkan ninu awọn ọmọ Ahimeleki ọmọ
Ahitubu ti a npè ni Abiatari si bọ́; o si sa
asala tọ Dafidi lọ.
21 Abiatari si fi han Dafidi pe, Saulu pa
awọn alufa Oluwa tan.
22 Dafidi si wi fun Abiatari pe, emi ti
mọ̀ ni ijọ na, nigbati Doegi ara Edomu nì
ti wà nibẹ̀ pe, nitotọ yio sọ fun Saulu:
nitori mi li a ṣe pa gbogbo idile baba rẹ.
23 Iwọ joko nihin lọdọ mi, máṣe bẹru,
nitoripe ẹniti nwá ẹmi mi, o nwá ẹmi rẹ:
ṣugbọn lọdọ mi ni iwọ o wà li ailewu.

## ORI 23.

NWỌN si wi fun Dafidi pe, Sa wõ awọn
ara Filistia mba ara Keila jagun,
nwọn si jà ilẹ ipakà wọnni li ole.
2 Dafidi si bere lọdọ Oluwa pe, Ki emi
ki o lọ kọlu awọn ara Filistia wọnyi bi?
Oluwa si wi fun Dafidi pe. Lọ, ki o si
kọlu awọn ara Filistia ki o si gbà Keila
silẹ.
3 Awọn ọmọkọnrin ti o wà lọdọ Dafidi
si wi fun u pe, Wõ, awa mbẹ̀ru nihinyi ni
Juda; njẹ yio ti ri nigbati awa ba de Keila
lati fi oju ko ogun awọn ara Filistia?
4 Dafidi si tun bere lọdọ Oluwa. Oluwa
si da a lohùn, o si wipe, Dide, ki o sọkalẹ
lọ si Keila, nitoripe emi o fi awọn ara
Filistia na le ọ lọwọ.
5 Dafidi ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si lọ si
Keila, nwọn si ba awọn ara Filistia jà,
nwọn si ko ohun ọsin wọn, nwọn si fi ipa-
run nla pa wọn. Dafidi si gbà awọn ara
Keila silẹ.
6 O si ṣe, nigbati Abiatari ọmọ Ahime-
leki fi sa tọ Dafidi lọ ni Keila, o sọkalẹ ton
ti efodu kan lọwọ rẹ̀,
7 A si sọ fun Saulu pe, Dafidi wa si
Keila. Saulu si wipe, Ọlọrun ti fi i le mi
lọwọ; nitoripe a ti dí i mọ tan, nitori o
wọ inu ilu ti o ni ilẹkun ati ikere.
8 Saulu si pe gbogbo awọn enia na jọ si
ogun, lati sọkalẹ lọ si Keila, lati ká Dafidi
mọ ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀.

Digitized by Google

9 Dafidi si mọ̀ pe Saulu ti gbèro buburu
si on; o si wi fun Abiatari alufa na pe,
Mu efodu na wá nihinyi.
10 Dafidi si wipe Oluwa Ọlọrun Israeli,
lõtọ ni iranṣẹ rẹ ti gbọ́ pe Saulu nwá ọ̀na
lati wá si Keila, lati wá fọ ilu na nitori
mi.
11 Awọn agba ilu Keila yio fi mi le e
lọwọ bi? Saulu yio ha sọkalẹ, gẹgẹ bi
iranṣẹ rẹ ti gbọ́ bi? Oluwa Ọlọrun Israeli,
emi bẹ̀ ọ, wi fun iranṣẹ rẹ. Oluwa si wipe,
Yio sọkalẹ wá.
12 Dafidi si wipe, Awọn agbà ilu Keila
yio fi emi ati awọn ọmọkọnrin mi le Saulu
lọwọ bi? Oluwa si wipe, Nwọn o fi ọ le
wọn lọwọ.
13 Dafidi ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ ti wọn
to ẹgbẹta enia si dide, nwọn lọ kuro ni
Keila, nwọn si lọ si ibikibi ti nwọn le lọ.
A si wi fun Saulu pe, Dafidi ti sá kuro ni
Keila; ko si lọ si Keila mọ.
14 Dafidi si ngbe ni aginju, nibiti o to
sa pamọ si, o si ngbe nibi oke-nla kan li
aginju Sifi. Saulu si nwá a lojojumọ, ṣu-
gbọn Ọlọrun ko fi le e lọwọ.
15 Dafidi si ri pe, Saulu ti jade lati wá
ẹmi on kiri: Dafidi si wà li aginju Sifi
ninu igbo kan.
16 Jonatani ọmọ Saulu si dide, o si tọ
Dafidi lọ ninu igbo na, o si gba a ni iyanju
nipa ti Ọlọrun.
17 On si wi fun u pe, Máṣe bẹru: nitori
ọwọ́ Saulu baba mi ki yio tẹ̀ ọ: iwọ ni yio
jọba lori Israeli, emi ni yio si ṣe ibikeji rẹ;
Saulu baba mi mọ̀ bẽ pẹlu.
18 Awọn mejeji si ṣe adehun niwaju
Oluwa; Dafidi si joko ninu igbo na.
Jonatani si lọ si ile rẹ̀.
19 Awọn ara Sifi si goke tọ Saulu wá si
Gibea, nwọn si wipe, Ṣe Dafidi ti fi ara rẹ̀
pamọ sọdọ wa ni ibi ti o to sa pamọ si ni
igbo, ni oke Hakila, ti o wà niha gusu ti
Jeṣimoni?
20 Njẹ nisisiyi, Ọba, sọkalẹ wá gẹgẹ bi
gbogbo ifẹ ti o wà li ọkàn rẹ lati sọkalẹ;
ipa ti awa ni lati fi i le ọba lọwọ.
21 Saulu si wipe, Alabukun fun li ẹnyin
nipa ti Oluwa; nitoripe ẹnyin ti kãnu fun
mi.
22 Lọ, emi bẹ̀ nyin, ẹ tun mura, ki ẹ si
mọ̀, ki ẹ si ri ibi ti ẹsẹ rẹ̀ gbe wà, ati ẹniti
o ri i nibẹ: nitoriti ati sọ fun mi pe, ọgbọ́n
li o nlò jọjọ.
23 Ẹ si wò, ki ẹ si mọ̀ ibi isapamọ ti
ima sapamọ si, ki ẹ si tun pada tọ mi wá,
nitori ki emi ki o le mọ̀ daju; emi o si ba
nyin lọ: yio si ṣe, bi o ba wà ni ilẹ Israeli,
emi o si wá a li awari ninu gbogbo ẹgbẹrun
Juda.
24 Nwọn si dide, nwọn si ṣaju Saulu lọ
si Sifi: ṣugbọn Dafidi ati awọn ọmọkọnrin
rẹ̀ wà li aginju Maoni, ni pẹtẹlẹ niha gusu
ti Jeṣimoni.
25 Saulu ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si lọ
iwá a. Nwọn si sọ fun Dafidi: o si sọkalẹ
wá si ibi okuta kan, o si joko li aginju ti
Maoni. Saulu si gbọ́, o si lepa Dafidi li
aginju Maoni.
26 Saulu si nrin li apakan oke kan,
Dafidi ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ li apa keji
oke na: Dafidi si yara lati sa kuro niwaju
Saulu; nitoripe Saulu ati awọn ọmọkọnrin
rẹ̀ ti rọ̀gba yi Dafidi ati awọn ọmọkọnrin
rẹ̀ ka lati mu wọn.
27 Ṣugbọn onṣẹ kan si tọ Saulu wá, o si
wipe, iwọ yara ki o si wá, nitoriti awọn
Filistini ti gbe ogun ti ilẹ wa.
28 Saulu si pada kuro ni lilepa Dafidi, o
si lọ ipade awọn Filistini: nitorina ni
nwọn si se npe ibẹ̀ na ni Selahammalekoti.
(ni itumọ rẹ̀, okuta ipinyà.)
29 Dafidi ti goke lati ibẹ lọ, o si joko
nibi ti o sapamọ si ni Engedi.

## ORI 24.

O SI ṣe nigbati Saulu pada kuro lẹhin
awọn Filistini, a si sọ fun u pe, Wõ,
Dafidi mbẹ ni aginju Engedi.
2 Saulu si mu ẹgbẹdogun akọni ọkọnrin
ti a yàn ninu gbogbo Israeli, o si lọ lati wá
Dafidi ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ lori okuta
awọn ewurẹ igbẹ.
3 O si de ibi awọn agbo agutan ti o wà
li ọ̀na, ihò kan si wà nibẹ, Saulu si wọ inu
rẹ̀ lọ lati bo ẹsẹ rẹ̀: Dafidi ati awọn ọmọ-
kọnrin rẹ̀ si mbẹ lẹba iho na.
4 Awọn ọmọkọnrin Dafidi si wi fun u pe,
Wõ, eyi li ọjọ na ti Oluwa wi fun ọ pe,
Wõ, emi o fi ọta rẹ le ọ li ọwọ́, iwọ o si ṣe
si i gẹgẹ bi o ti tọ li oju rẹ. Dafidi si dide,
o si yọ lọ ike eti aṣọ Saulu.
5 O si ṣe lẹhin eyi, aiya já Dafidi nitoriti
on ke eti aṣọ Saulu.
6 On si wi fun awọn ọmọkọnrin rẹ̀ pe,
Ẽwọ̀ ni fun mi lati ọdọ Oluwa wá bi emi ba
ṣe nkan yi si oluwa mi, ẹniti a ti fi ami
ororo Oluwa yàn, lati nàwọ́ mi si i, nitoripe
ẹni-ami-ororo Oluwa ni.
7 Dafidi si fi ọ̀rọ wọnyi da awọn ọmọ-
kọnrin rẹ̀ duro, ko si jẹ ki wọn dide si
Saulu. Saulu si dide kuro ni iho na, o si
ba ọ̀na rẹ̀ lọ.

Digitized by Google

8 Dafidi si dide lẹhin na, o si jade kuro
ninu iho na, o si kọ si Saulu pe, Oluwa
mi, ọba. Saulu si wo ẹhin rẹ̀, Dafidi si
doju rẹ̀ bo ilẹ, o si tẹriba fun u.
9 Dafidi si wi fun Saulu pe, Eha ti se ti
iwọ fi ngbọ́ ọ̀rọ awọn enia pe, Wõ, Dafidi
nwá ẹmi rẹ ?
10 Wõ, oju rẹ ri loni, bi Oluwa ti fi iwọ
le mi li ọwọ́ loni ni iho nì : awọn kan ni ki
emi ki o pa ọ : ṣugbọn emi dá ọ si ; emi si
wipe, emi ki yio nawọ́ mi si oluwa mi,
nitoripe ẹni-ami-ororo Oluwa li on iṣe.
11 Pẹlupẹlu, baba mi, wõ, ani wo eti aṣọ
rẹ li ọwọ́ mi ; nitori emi ke eti aṣọ rẹ, emi
ko si pa ọ, si wò, ki o si mọ̀ pe, kò si ibi
tabi ẹ̀ṣẹ li ọwọ́ mi, emi kò si ṣẹ̀ ọ, ṣugbọn
iwọ ndọdẹ ẹmi mi lati gba a.
12 Ki Oluwa ki o ṣe idajọ larin emi ati
iwọ, ati ki Oluwa ki o gbẹsan mi lara rẹ ;
ṣugbọn ọwọ́ mi ki yio si lara rẹ.
13 Gẹgẹ bi owe igba atijọ ti wi, Iwabu-
buru a ma ti ọdọ awọn enia buburu jade
wá ; ṣugbọn ọwọ́ mi kì yio si lara rẹ.
14 Nitori tani ọba Israeli fi jade ? tani
iwọ nlepa ? okú aja, tabi eṣinṣin ?
15 Ki Oluwa ki o ṣe onidajọ, ki o si
dajọ larin emi ati iwọ, ki o si wò ki o
gbejà mi, ki o si gbà mi kuro li ọwọ́ rẹ.
16 O si ṣe, nigbati Dafidi si dakẹ ọ̀rọ
wọnyi isọ fun Saulu, Saulu si wipe, Ohùn
rẹ li eyi bi, Dafidi ọmọ mi ? Saulu si gbe
ohùn rẹ̀ soke, o sọkun.
17 O si wi fun Dafidi pe, iwọ ṣe olododo
jù mi lọ : nitoripe iwọ ti fi ire san fun mi,
emi fi ibi san fun ọ.
18 Iwọ si fi ore ti iwọ ti ṣe fun mi hàn
loni : nigbati o jẹ pe, Oluwa ti fi emi le ọ
li ọwọ́, iwọ kò si pa mi.
19 Nitoripe bi enia ba ri ọta rẹ̀, o le jẹ
ki o lọ li alafia bi ? Oluwa yio si fi ire san
eyi ti iwọ ṣe fun mi loni.
20 Wõ, emi mọ̀ nisisiyi pe, nitotọ iwọ o
jẹ ọba, ilẹ-ọba Israeli yio si fi idi mulẹ si ọ
lọwọ.
21 Si bura fun mi nisisiyi li orukọ Olu-
wa, pe, iwọ kì yio ke iru mi kuro lẹhin mi,
ati pe, iwọ ki yio pa orukọ mi run kuro ni
idile baba mi.
22 Dafidi si bura fun Saulu. Saulu si lọ
si ile rẹ̀ ; ṣugbọn Dafidi ati awọn ọmọkọn-
rin rẹ̀ si goke lọ si iho na.

## ORI 25.

SAMUELI si kú ; gbogbo enia Israeli si
ko ara wọn jọ, nwọn si sọkun rẹ̀, nwọn
si sin i ninu ile rẹ̀ ni Rama. Dafidi si dide,
o si sọkalẹ lọ si ijù Parani.
2 Ọkọnrin kan si mbẹ ni Maoni, ẹniti
iṣẹ rẹ̀ mbẹ ni Karmeli ; ọkọnrin na si pọ̀
gidigidi, o si ni ẹgbẹdogun agutan, ati
ẹgbẹrun ewurẹ : o si nrẹ irun agutan rẹ̀
ni Karmeli.
3 Orukọ ọkọnrin na si njẹ Nabali, orukọ
aya rẹ̀ si njẹ Abigaili ; on si jẹ oloye obirin,
ati arẹwa enia ; ṣugbọn onroro ati oniwa
buburu ni ọkọnrin ; ẹni idile Kalebu li on
si ṣe.
4 Dafidi si gbọ́ li aginju pe, Nabali nrẹ
irun agutan rẹ̀.
5 Dafidi si ran ọmọkọnrin mẹwa, Dafidi
si sọ fun awọn ọdọmọkọnrin na pe, Ẹ goke
lọ si Karmeli, ki ẹ si tọ Nabali lọ, ki ẹ si
ki i li orukọ mi.
6 Bayi li ẹ o si wi fun ẹniti o wà ni irọra
pe, Alafia fun ọ, alafia fun ile rẹ, ati alafia
fun ohun gbogbo ti iwọ ni.
7 Njẹ mo gbọ́ pe, awọn olùrẹrun mbẹ
lọdọ rẹ ; Wõ, awọn oluṣọ agutan rẹ ti wà
lọdọ wa, awa kò ṣe wọn ni iwọsi kan, bẽni
ohun kan kò si nù lọwọ wọn, ni gbogbo
ọjọ ti nwọn wà ni Karmeli.
8 Bi awọn ọmọkọnrin rẹ lere, nwọn o si
sọ fun ọ. Nitorina jẹ ki awọn ọmọkọnrin
wọnyi ki o ri oju rere lọdọ rẹ ; nitoripe
awa sa wá li ọjọ rere : emi bẹ ọ, ohunkohun
ti ọwọ́ rẹ ba bá, fi fun awọn iranṣẹ rẹ, ati
fun Dafidi ọmọ rẹ.
9 Awọn ọmọkọnrin Dafidi si lọ, nwọn si
sọ fun Nabali gẹgẹ bi gbogbo ọ̀rọ wọnyi li
orukọ Dafidi, nwọn si simi.
10 Nabali si da awọn iranṣẹ Dafidi lo-
hùn, pe, Tani ijẹ Dafidi ? tabi tani si njẹ
ọmọ Jesse ? ọ̀pọlọpọ iranṣẹ ni mbẹ nisisiyi
ti nwọn sá olukuluku kuro lọdọ oluwa rẹ̀.
11 Njẹ ki emi ki o ha mu onjẹ mi, ati
omi mi, ati ẹran mi ti mo pa fun awọn olù-
rẹrun mi, ki emi ki o si fi fun awọn ọkọnrin
ti emi kò mọ̀ ibi ti nwọn gbe ti wá ?
12 Bẽli awọn ọmọkọnrin Dafidi si mu
ọ̀na wọn pọ̀n, nwọn si pada, nwọn si wá,
nwọn si rò fun u gẹgẹ bi gbogbo ọ̀rọ wọnyi.
13 Dafidi si wi fun awọn ọmọkọnrin rẹ̀
pe, Ki olukuluku nyin ki o di idà rẹ̀ mọ
idi. Olukuluku ọkọnrin si di idà rẹ̀ mọ
idi ; ati Dafidi pẹlu si di idà tirẹ̀ : iwọn
irinwo ọmọkọnrin si goke tọ Dafidi lẹhin ;
igba si joko nibi ẹrù.
14 Ọkan ninu awọn ọmọkọnrin Nabali
si wi fun Abigaili aya rẹ̀ pe, Wõ, Dafidi
ran onṣẹ lati aginju wá lati ki oluwa wa ;
o si kanra mọ wọn.

Digitized by Google

15 Şugbọn awọn ọkọnrin na şe ore fun
wa gidigidi, nwọn kò şe wa ni iwọsi kan;
ohunkohun kò nù li ọwọ́ wa, ni gbogbo ọjọ
ti awa ba wọn rìn nigbati awa mbẹ li oko.
16 Odi ni nwọn sa jasi fun wa lọsan, ati
loru, ni gbogbo ọjọ ti a fi ba wọn gbe, ti a
mbojuto awọn agutan.
17 Njẹ si ro o wò, ki o si mọ̀ eyiti iwọ o
şe; nitoripe ati gbero ibi si oluwa wa, ati
si gbogbo ile rẹ̀: on si jasi ọmọ Beliali ti a
ko le sọ̀rọ fun.
18 Abigaili si yara, o si mu igba işu
akara ati igo ọti-waini meji, ati agutan
marun, ti a ti sè, ati oşuwọn agbado yiyan
marun, ati ọgọrun idi ajara, ati igba akara
eso ọpọtọ, o si di wọn ru kẹtẹkẹtẹ.
19 On si wi fun awọn ọmọkọnrin rẹ̀ pe,
Ma lọ niwaju mi; wõ, emi mbọ lẹhin nyin.
Şugbọn on kò wi fun Nabali bale rẹ̀.
20 O si şe, bi o ti gun ori kẹtẹkẹtẹ, ti o
si nsọkalẹ si ibi ikọkọ oke na, wõ, Dafidi
ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si nsọkalẹ niwaju
rẹ̀; on si wá pade wọn.
21 Dafidi si ti wipe, Njẹ lasan li emi ti
pa gbogbo eyi ti işe ti eleyi mọ li aginju,
ti ohunkohun kò si nù ninu gbogbo eyi ti
işe tirẹ̀; on li o si fi ibi san ire fun mi yi.
22 Bẽ ati ju bẽ lọ ni ki Ọlọrun ki o şe
si awọn ọta Dafidi, bi emi ba fi ẹnikẹni ti
ntọ̀ sara ogiri silẹ ninu gbogbo eyi ti işe
tirẹ̀ titi di imọlẹ owurọ.
23 Abigaili si ri Dafidi, on si yara, o
sọkalẹ lori kẹtẹkẹtẹ, o si dojubolẹ niwaju
Dafidi, o si tẹ ara rẹ̀ ba silẹ.
24 O si wolẹ li ẹba ẹsẹ rẹ̀ o wipe, Oluwa
mi, fi ẹ̀şẹ yi ya mi: ki o si jẹ ki iranşẹbirin
rẹ, emi bẹ̀ ọ, sọ̀rọ leti rẹ, ki o si gbọ́ ọ̀rọ
iranşẹbirin rẹ.
25 Oluwa mi, emi bẹ̀ ọ, má ka ọkọnrin
Beliali yi si, ani Nabali: nitoripe bi orukọ
rẹ̀ ti jẹ bẽli on na ri: Nabali li orukọ rẹ̀,
aimoye si wà pẹlu rẹ̀; şugbọn emi iranşẹ-
birin rẹ kò ri awọn ọmọkọnrin oluwa mi,
ti iwọ rán.
26 Njẹ, oluwa mi, bi Oluwa ti wà lãye,
ati bi ẹmi rẹ si ti wà làye, bi Oluwa si ti
da ọ duro lati wá ta ẹjẹ silẹ, ati lati fi ọwọ́
ara rẹ gbẹsan; njẹ, ki awọn ọta rẹ, ati
awọn ẹniti ngbero ibi si oluwa mi ri bi
Nabali.
27 Njẹ eyi ni ẹbùn ti iranşẹbirin rẹ mu
wá fun oluwa mi, jẹ ki a si fi fun awọn
ọmọkọnrin ti ntọ oluwa mi lẹhin.
28 Emi bẹ̀ ọ, fi irekọja iranşẹbirin rẹ ji
i: nitori ti Oluwa yio sa şe ile ododo fun
oluwa mi, nitori ogun Oluwa ni oluwa mi
njà; a kò si ri ibi lọwọ rẹ ni gbogbo ọjọ
rẹ.
29 Ọkọnrin kan si dide lati ma lepa rẹ,
ati lati ma wá ẹmi rẹ: şugbọn a o si di
ẹmi oluwa mi ninu idi ìye lọdọ Oluwa
Ọlọrun rẹ; ati ẹmi awọn ọta rẹ li a o si
gbọ̀n sọnù gẹgẹ bi kànakana jade.
30 Yio si şe, Oluwa yio şe si oluwa mi
gẹgẹ bi gbogbo ire ti o ti wi nipa tirẹ, yio
si yan ọ li alaşẹ lori Israeli.
31 Eyi ki yio si jasi ibinujẹ fun ọ, tabi
ibinujẹ ọkàn fun oluwa mi, nitoripe iwọ ta
ẹjẹ alaişẹ silẹ, tabi pe oluwa mi gbẹsan fun
ara rẹ̀: şugbọn nigbati Oluwa ba şe ore
fun oluwa mi, njẹ ranti iranşẹbirin rẹ.
32 Dafidi si wi fun Abigaili pe, Alabukun
fun Oluwa Ọlọrun Israeli, ti o ran ọ loni yi
lati pade mi.
33 Ibukun ni fun ọgbọn rẹ, alabukun
si ni iwọ, ti o da mi duro loni yi lati wá
ta ẹjẹ silẹ, ati lati fi ọwọ́ mi gbẹsan fun
ara mi.
34 Nitõtọ bi Oluwa Ọlọrun Israeli ti
mbẹ, ti o da mi duro lati pa ọ lara, biko-
şepe bi iwọ ti yara ti o si ti wá pade mi,
nitotọ ki ba ti kù fun Nabali di imọlẹ
owurọ ninu awọn ti o ntọ̀ sara ogiri.
35 Bẽni Dafidi si gbà nkan ti o mu wá
fún u li ọwọ́ rẹ̀, o si wi fun u pe, Goke lọ
li alafia si ile rẹ, wõ, emi ti gbọ́ ohun rẹ,
inu mi si dùn si ọ.
36 Abigaili si tọ̀ Nabali wá, si wõ, on si
se asè ni ile rẹ̀ gẹgẹ bi ase ọba; inu Nabali
si dùn nitoripe, o ti mu ọti li amupara;
on kò si sọ nkan fun u, diẹ tabi pupọ: titi
di imọlẹ owurọ.
37 O si şe; li owurọ, nigbati ọti na si
dá tan li oju Nabali, obirin rẹ̀ si rò nkan
wọnni fun u, ọkàn rẹ̀ si kú ninu, on si dabi
okuta.
38 O si şe lẹhin ìwọn ijọ mẹwa, Oluwa
lù Nabali, o si kú.
39 Dafiidi si gbọ́ pe Nabali kú, o si wi
pe, Iyin ni fun Oluwa ti o gbeja gigàn mi
lati ọwọ́ Nabali wá, ti o si da iranşẹ rẹ̀
duro lati şe ibi: Oluwa si yi ikà Nabali si
ori on tikalarẹ̀. Dafidi si ranşẹ, o si ba
Abigaili sọ̀rọ lati mu u fi şe aya fun ara rẹ̀.
40 Awọn iranşẹ Dafidi si lọ sọdọ Abi-
gaili ni Karmeli, nwọn si sọ fun u pe,
Dafidi rán wa wá si ọ lati mu ọ şe aya rẹ̀.
41 O si dide, o si dojubolẹ, o si wipe,
Wõ, jẹ ki iranşẹbirin rẹ ki o jẹ iranşẹ kan
lati ma wẹ ẹsẹ awọn iranşẹ ọluwa mi.
42 Abigaili si yara, o si dide, o si gun
kẹtẹkẹtẹ, awọn iranşẹbirin rẹ̀ marun si tẹle

Digitized by Google

e lẹhin; on si tẹle awọn iranṣẹ Dafidi, o
si wa di aya rẹ̀.
43 Dafidi si mu Ahinoamu ti Jesreeli;
awọn mejeji si jẹ aya rẹ̀.
44 Ṣugbọn Saulu ti fi Mikali ọmọ rẹ̀
obirin, aya Dafidi, fun Falti ọmọ Laisi ti
iṣe ara Gallimu.

## ORI 26.

AWỌN ara Sifi si tọ̀ Saulu wá si Gibea,
nwọn wipe, Ṣe Dafidi fi ara rẹ̀ pamọ
nibi oke Hakila, eyi ti o wà niwaju Jeṣi-
moni?
2 Saulu si dide o si sọkalẹ lọ si ijù Sifi,
ẹgbẹ̀dogun ààyàn enia ni Israeli si pẹlu rẹ̀
lati wá Dafidi ni iju Sifi.
3 Saulu si pagọ rẹ̀ ni ibi oke Hakila ti
o wà niwaju Jeṣimoni li oju ọ̀na. Dafidi
si joko ni ibi iju na, o si ri pe Saulu ntẹle
on ni iju na.
4 Dafidi si ran amí jade, o si mọ̀ nitõtọ
pe Saulu mbọ̀.
5 Dafidi si dide, o si wá si ibi ti Saulu
pagọ si: Dafidi si ri ibi ti Saulu gbe dubulẹ
si, ati Abneri ọmọ Neri, olori ogun rẹ̀:
Saulu si dubulẹ larin awọn kẹ̀kẹ́, awọn
enia na si pagọ wọn yi i ka.
6 Dafidi si dahun, o si wi fun Ahimeleki
ọkan ninu awọn ọmọ Heti, ati fun Abiṣai
ọmọ Seruia ẹgbọn Joabu, pe, Tani o ba mi
sọkalẹ lọ sọdọ Saulu ni ibudo? Abiṣai si
wipe, emi o ba ọ sọkalẹ lọ.
7 Bẽni Dafidi ati Abiṣai si tọ awọn enia
na wá li oru: si wõ, Saulu dubulẹ o si
nsun larin kẹkẹ, a si fi ọ̀kọ rẹ̀ gunlẹ ni ibi
timtim rẹ̀: Abneri ati awọn enia na si
dubulẹ yi i ka.
8 Abiṣai si wi fun Dafidi pe, Ọlọrun ti
fi ọta rẹ le ọ lọwọ loni: njẹ, emi bẹ ọ, sa
jẹ ki emi ki o fi ọ̀kọ gun u mọlẹ lẽkan, emi
ki yio gun u lẽmeji.
9 Dafidi si wi fun Abiṣai pe, Máṣe pa a:
nitoripe tani le nawọ́ rẹ̀ si ẹni-àmi-ororo
Oluwa ki o si wà laijẹbi?
10 Dafidi si wipe, bi Oluwa ti mbẹ
Oluwa yio pa a, tabi ọjọ rẹ̀ yio si pe ti yio
kú, tabi on o sọkalẹ lọ si ibi ijà, a si ṣegbe
nibẹ.
11 Oluwa má jẹ ki emi nà ọwọ́ mi si
ẹni-àmi-ororo Oluwa: njẹ, emi bẹ ọ, mu
ọ̀kọ na ti mbẹ nibi timtim rẹ̀, ati igo omi
ki a si ma lọ.
12 Dafidi si mu ọ̀kọ na, ati igo omi na
kuro nibi timtim Saulu: nwọn si ba ti
wọn lọ, kò si si ẹnikan ti o ri i, tabi ti o
mọ̀; kò si si ẹnikan ti o ji; gbogbo wọn
si sùn; nitoripe orun àjika lati ọdọ Oluwa
wá ti ṣubu lù wọn.
13 Dafidi si rekọja si iha keji, o si duro
lori oke kan ti o jina rere; afo nla kan si
wà lagbedemeji wọn:
14 Dafidi si kọ si awọn enia na, ati si
Abneri ọmọ Neri wipe, Iwọ kò dahun,
Abneri? Nigbana ni Abneri si dahun wipe,
Iwọ tani npe ọba?
15 Dafidi si wi fun Abneri pe, Alagbara
ọkọnrin ki iwọ nṣe ndan? tali o si dabi
iwọ ni Israeli? njẹ ẽṣe ti iwọ ko tọju ọba
oluwa rẹ? nitori ẹnikan ninu awọn enia na
ti wọle wá lati pa ọba oluwa rẹ.
16 Nkan ti iwọ ṣe yi kò dara. Bi Oluwa
ti mbẹ, o tọ ki ẹnyin ki o kú, nitoripe
ẹnyin ko pa oluwa nyin mọ, ẹni-àmi-ororo
Oluwa. Njẹ si wo ibiti ọ̀kọ ọba gbe wà,
ati igò omi ti o ti wà nibi timtim rẹ.
17 Saulu si mọ̀ ohùn Dafidi, o si wipe,
Ohùn rẹ li eyi bi, Dafidi ọmọ mi? Dafidi
si wipe, Ohùn mi ni, oluwa mi, ọba.
18 On si wipe, Nitori kini oluwa mi ṣe
nlepa iranṣẹ rẹ? kili emi ṣe? tabi ìwa
buburu wo li o wà li ọwọ́ mi.
19 Njẹ emi bẹ ọ ọba, oluwa mi, gbọ́ ọ̀rọ
iranṣẹ rẹ. Bi Oluwa ba ti ru iwọ soke si
mi, jẹ ki on ki o gbà ẹbọ; ṣugbọn bi o ba
si ṣepe ọmọ enia ni, ifibu ni ki nwọn ki o
jasi niwaju Oluwa; nitori nwọn le mi jade
loni ki emi má gbe inu ilẹ ini Oluwa, wipe,
Lọ, sin awọn ọlọrun miran.
20 Njẹ máṣe jẹ ki ẹjẹ mi ki o ṣàn silẹ
niwaju Oluwa: nitori ọba Israeli jade lati
wá itapin bi ẹni ndọdẹ aparo lori oke-nla.
21 Saulu si wipe, Emi ti dẹṣẹ: yipada,
Dafidi ọmọ mi: nitoripe emi kì yio wá ibi
rẹ mọ, nitoriti ẹmi mi sa ti ṣe iyebiye li oju
rẹ loni: wõ, emi ti nhuwa wère mo si ti ṣina
jọjọ.
22 Dafidi si dahun, o si wipe, Wo ọ̀kọ
ọba! ki o si jẹ ki ọkan ninu awọn ọmọ-
kọnrin rekọja wá gbà a.
23 Ki Oluwa ki o san a fun olukuluku
ododo rẹ̀ ati otitọ rẹ̀: nitoripe Oluwa ti fi
ọ le mi lọwọ loni, ṣugbọn emi ko fẹ nawọ́
mi si ẹni-àmi-ororo Oluwa.
24 Si wõ, gẹgẹ bi ẹmi rẹ ti tobi loni loju
mi, bẹni ki emi mi ki o tobi loju Oluwa,
ki o si gbà mi lọwọ ibi gbogbo.
25 Saulu si wi fun Dafidi pe, Alabu-
kunfun ni iwọ, Dafidi ọmọ mi: nitõtọ iwọ
o si ṣe nkan nla, nitotọ iwọ o si bori. Da-
fidi si ba ọ̀na rẹ̀ lọ, Saulu si yipada si
ibugbe rẹ̀.



Digitized by Google

## ORI 27.

DAFIDI si wi li ọkàn ara rẹ̀ pe, njẹ ni ijọ kan l'emi o ti ọwọ́ Saulu ṣegbe, ko si si ohun ti o yẹ mi jù ki emi ki o yara sa asala lọ si ilẹ awọn Filistini: yio su Saulu lati ma tun wá mi kiri ni gbogbo agbegbe Israeli: emi a si bọ li ọwọ́ rẹ̀.

2 Dafidi si dide, o si rekọja, on ati ẹgbẹta ọmọkọnrin ti o mbẹ lọdọ rẹ̀ si Akiṣi, ọmọ Maoki, ọba Gati.

3 Dafidi si ba Akiṣi joko ni Gati, on, ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀, olukuluku wọn ti on ti ara ile rẹ̀; Dafidi pẹlu awọn aya rẹ̀ mejeji, Ahinoamu ara Jesreeli, ati Abigaili ara Karmeli aya Nabali.

4 A si sọ fun Saulu pe, Dafidi sa lọ si Gati: on ko si tun wá a kiri mọ.

5 Dafidi si wi fun Akiṣi pe, Bi o ba jẹ pe emi ri ore ọfẹ loju rẹ, jẹ ki wọn ki o fun mi ni ibi kan ninu awọn ileto wọnni; emi o ma gbe ibẹ: ẽṣe ti iranṣẹ rẹ yio si ma ba ọ gbe ni ilu ọba?

6 Akiṣi si fi Siklagi fun u ni ijọ na; nitorina ni Siklagi fi di ti awọn ọba Juda titi o fi di oni yi.

7 Iye ọjọ ti Dafidi fi joko ni ilu awọn Filistini si jẹ ọdun kan ati oṣu mẹrin.

8 Dafidi ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si goke lọ, nwọn si gbe ogun ti awọn ara Geṣuri, ati awọn ara Gesra, ati awọn ara Amaleki: awọn wọnyi li o si ti ngbe ni ilẹ na nigba atijọ, bi iwọ ti nlọ si Ṣuri titi o fi de ilẹ Egipti.

9 Dafidi si kọlu ilẹ na, ko si fi ọkọnrin tabi obirin silẹ lãye, o si ko agùtan, ati malu, ati kẹtẹkẹtẹ, ati ibakasie, ati aṣọ, o si yipada o si tọ Akisi wá.

10 Akiṣi si bi i pe, Nibo li ẹnyin gbe rìn si loni? Dafidi si dahun pe, Siha gusun ti Juda ni, ati siha gusun ti Jerameeli, ati siha gusun ti awọn ara Keni:

11 Dafidi kò si da ọkọnrin tabi obirin si lãye, lati mu ihin wá si Gati, wipe, Ki nwọn ki o má ba sọ ọ̀rọ wa nibẹ, pe, Bayi ni Dafidi ṣe, ati bẽni iṣe rẹ̀ yio si ri ni gbogbo ọjọ ti yio fi joko ni ilu awọn Filistini.

12 Akiṣi si gba ti Dafidi gbọ́, wipe, On ti mu ki Israeli ati awọn enia rẹ̀ korira rẹ̀ patapata, yio si jẹ iranṣẹ mi titi lai.

## ORI 28.

O SI ṣe, ni ijọ wọnni, awọn Filistini si ko awọn ogun wọn jọ, lati ba Israeli jà. Akiṣi si wi fun Dafidi pe, Mọ̀ daju daju pe, iwọ o ba mi jade lọ si ibi ija, iwọ ati awọn ọmọkọnrin rẹ.

2 Dafidi si wi fun Akiṣi pe, Nitotọ iwọ o si mọ̀ ohun ti iranṣẹ rẹ le ṣe. Akiṣi si wi fun Dafidi pe, Nitorina li emi o ṣe fi iwọ ṣe oluṣọ ori mi ni gbogbo ọjọ.

3 Samueli sì ti kú, gbogbo Israeli si ṣọkun rẹ̀, nwọn si sin i ni Rama ni ilu rẹ̀. Saulu si ti mu awọn abokusọ̀rọ-ọkọnrin, ati awọn abokusọ̀rọ-obirin kuro ni ilẹ na.

4 Awọn Filistini si ko ara wọn jọ, nwọn wá, nwọn si do si Ṣunemu: Saulu si ko gbogbo Israeli jọ, nwọn si tẹdo ni Gilboa.

5 Nigbati Saulu si ri ogun awọn Filistini na, on si bẹ̀ru, aiya rẹ̀ si wariri gidigidi.

6 Nigbati Saulu si bere lọdọ Oluwa, Oluwa kò da a lohùn nipa alá, nipa Urimu tabi nipa awọn woli.

7 Saulu si wi fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe, Ẹ ba mi wá obirin kan ti o ni ẹmi abokusọ̀rọ, emi o si tọ ọ lọ, emi o si bere lọdọ rẹ̀. Awọn iranṣẹ rẹ̀ si wi fun u pe, Wõ, obirin kan ni Endori ti o ni ẹmi abokusọ̀rọ.

8 Saulu si pa ara dà, o si mu aṣọ miran wọ̀, o si lọ, awọn ọmọkọnrin meji si pẹlu rẹ̀, nwọn si wá si ọdọ obirin na li oru: on si wipe, emi bẹ̀ ọ, fi ẹmi abokusọ̀rọ da nkan fun mi, ki o si mu ẹniti emi o darukọ rẹ̀ fun ọ wá oke fun mi.

9 Obirin na si da a lohùn pe, Wõ, iwọ sa mọ̀ ohun ti Saulu ṣe, bi on ti ke awọn abokusọ̀rọ obirin, ati awọn abokusọ̀rọ ọkọnrin kuro ni ilẹ na; njẹ eha ṣe ti iwọ dẹkùn fun ẹmi mi, lati mu ki nwọn pa mi?

10 Saulu si bura fun u nipa Oluwa, pe, Bi Oluwa ti mbẹ lãye, ìya kan ki yio jẹ ọ nitori nkan yi.

11 Obirin na si bi i pe, Tali emi o mu wá soke fun ọ? on si wipe, Mu Samueli goke fun mi wá.

12 Nigbati obirin na si ri Samueli, o kigbe lohùn rara: obirin na si ba Saulu sọrọ pe, ẽṣe ti iwọ fi tan mi jẹ? nitoripe Saulu ni iwọ iṣe.

13 Ọba si wi fun u pe, Máṣe bẹ̀ru; kini iwọ ri? obirin na si wi fun Sàulu pe, Emi ri ọlọrun kan nṣẹ́ ti ilẹ wá.

14 O si bi i pe, Ẽ ti ri? o si wipe, Ọkọnrin arugbo kan li o nṣẹ́ bọ̀; o si fi agbada bora. Saulu si mọ̀ pe, Samueli ni; o si tẹriba, o si wolẹ.

15 Samueli si wi fun Saulu pe, Eṣe ti iwọ fi yọ mi lẹnu lati mu mi wá oke? Saulu si dahun o si wipe, Ipọnju nla ba mi; nitoriti awọn Filistini mba mi ja-

Digitized by Google

gun, Ọlọrun si kọ̀ mi silẹ, kò si da mi
lohùn mọ, nipa ọwọ́ awọn woli, tabi nipa
alá; nitorina li emi si ṣe pè ọ, ki iwọ ki
ole fi ohun ti emi o ṣe hàn mi.
16 Samueli si wipe, O ti ṣe bi mi lere
nigbati o jẹ pe, Oluwa ti kọ̀ ọ silẹ, o si wa
di ọta rẹ?
17 Oluwa si ṣe fun ara rẹ̀ gẹgẹ bi o ti ti
ipa ọwọ́ mi sọ: Oluwa si yà ijọba na kuro
li ọwọ́ rẹ, o si fun aladugbo rẹ, ani Dafidi.
18 Nitoripe iwọ kò gbọ́ ohùn Oluwa,
iwọ kò si ṣe iṣẹ ibinu rẹ̀ si Amaleki, ni-
torina li Oluwa si ṣe nkan yi si ọ loni yi:
19 Oluwa yio si fi Israeli pẹlu iwọ le
awọn Filistini lọwọ: li ọla ni iwọ ati awọn
ọmọ rẹ ọkọnrin yio pẹlu mi: Oluwa yio si
fi ogun Israeli le awọn Filistini lọwọ́.
20 Lojukanna ni Saulu ṣubu lulẹ gbọrọ
bi o ti gùn, ẹ̀ru si bà a gidigidi, nitori ọ̀rọ
Samueli; agbara kò si si fun u: nitoripe
kò jẹun li ọjọ na t'ọsan t'oru.
21 Obirin na si tọ Saulu wá, o si ri i pe
o wà ninu ibanujẹ pupọ, o si wi fun u pe,
Wõ, iranṣẹbirin rẹ ti gbọ́ ohùn rẹ, emi si ti
fi ẹmi mi si ọwọ́ mi, emi si ti gbọ́ ọ̀rọ ti
iwọ sọ fun mi.
22 Njẹ, nisisiyi, emi bẹ ọ, gbọ́ ohùn
iranṣẹbirin rẹ, emi o si fi onjẹ diẹ siwaju
rẹ; si jẹun, iwọ o si li agbara, nigbati iwọ
ba nlọ li ọ̀na.
23 Ṣugbọn on kọ̀, o si wipe, Emi kì yio
jẹun. Ṣugbọn awọn iranṣẹ rẹ̀, pẹlu obirin
na si rọ̀ ọ; on si gbọ́ ohùn wọn. O si
dide kuro ni ilẹ, o si joko lori akete.
24 Obirin na si ni ẹgbọrọ malu kan ti o
sanra ni ile; o si yara, o pa a o si mu iyẹ-
fun, o si pò o, o si fi ṣe akara aiwu.
25 On si mu u wá siwaju Saulu, ati si-
waju awọn iranṣẹ rẹ̀; nwọn si jẹun. Nwọn
si dide, nwọn lọ li oru na.

## ORI 29.

AWỌN Filistini si ko gbogbo ogun wọn
jọ si Afeki: Israeli si do ni ibi isun
omi ti o wà ni Jesreeli.
2 Awọn ijoye Filistini si kọja li ọrọrun
ati li ẹgbẹgbẹrun: Dafidi ati awọn ọmọ-
kọnrin rẹ̀ pẹlu Akiṣi si kẹhin.
3 Awọn ijoye Filistini si bere wipe, Kini
awọn Heberu nṣe nihinyi? Akiṣi si wi fun
awọn ijoye Filistini pe, Dafidi kọ yi,
iranṣẹ Saulu ọba Israeli, ti o wà lọdọ mi
lati ọjọ wọnyi tabi lati ọdun wọnyi, emi
ko iti ri iṣiṣe kan li ọwọ́ rẹ̀ lati ọjọ ti o
ti de ọdọ mi titi di oni yi.
4 Awọn ijoye Filistini si binu si i;
awọn ijoye Filistini si wi fun u pe, jẹ ki
ọkọnrin yi pada ki o si lọ si ipò rẹ̀ ti o fi
fun u, ki o má si jẹ ki o ba wa sọkalẹ lọ si
ogun, ki o má ba jasi ọta fun wa li ogun;
Kini on o fi ba oluwa rẹ̀ laja, ori awọn
enia wọnyi kọ?
5 Ṣe eyi ni Dafidi ti nwọn tori rẹ̀ gberin
ara wọn ninu ijo wipe, Saulu pa ẹgbẹgbẹrun
rẹ̀, Dafidi si pa ẹgbẹgbãrun tirẹ̀?
6 Akiṣi si pe Dafidi, o si wi fun u pe, bi
Oluwa ti mbẹ lãye, iwọ jẹ olõtọ ati ẹni ìwa
rere loju mi, ni alọ rẹ ati abọ̀ rẹ pẹlu mi li
ogun; nitoripe emi ko iti ri buburu kan
lọwọ rẹ lati ọjọ ti iwọ ti tọ̀ mi wá, titi o fi
di oni yi: ṣugbọn loju awọn ijoye iwọ kò
ṣe ẹni ti o tọ́.
7 Njẹ yipada ki o si ma lọ li alafia, ki
iwọ ki o má ba ṣe ibanujẹ fun awọn
Filistini.
8 Dafidi si wi fun Akiṣi pe, Kili emi ṣe?
kini iwọ si ri lọwọ iranṣẹ rẹ lati ọjọ ti emi
ti gbe niwaju rẹ titi di oni yi, ti emi kì yio
fi lọ ba awọn ọta ọba ja?
9 Akiṣi si dahun o si wi fun Dafidi pe,
Emi mọ̀ pe iwọ ṣe ẹni-rere loju mi, bi
angeli Ọlọrun: ṣugbọn awọn ijoye Filistini
wi pe, On kì yio ba wa lọ si ogun.
10 Njẹ, nisisiyi dide li owurọ pẹlu awọn
iranṣẹ oluwa rẹ ti o ba ọ wá: ki ẹ si dide li
owurọ nigbati ilẹ ba mọ́, ki ẹ si ma lọ.
11 Dafidi ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si dide
li owurọ lati pada lọ si ilẹ awọn Filistini.
Awọn Filistini si goke lọ si Jesreeli.

## ORI 30.

OSI ṣe, nigbati Dafidi ati awọn ọmọ-
kọnrin rẹ̀ si bọ̀ si Siklagi ni ijọ kẹta,
awọn ara Amaleki si ti kọlu ihà ariwa, ati
Siklagi, nwọn si ti kun u;
2 Nwọn si ko awọn obirin ti mbẹ ninu
rẹ̀ ni igbekun, nwọn kò si pa ẹnikan,
ọmọde tabi agbà, ṣugbọn nwọn ko nwọn lọ,
nwọn si ba ọ̀na ti nwọn lọ.
3 Dafidi ati awọn ọmọkọnrin si wọ ilu,
si wõ, a ti kun u; ati obirin wọn, ati
ọmọkọnrin wọn ati ọmọbirin wọn li a kó ni
igbèkun lọ.
4 Dafidi ati awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀ si
gbe ohùn wọn soke, nwọn si sọkun titi
agbara kò si si fun wọn mọ lati sọkun.
5 A si kó awọn aya Dafidi mejeji nigbè-
kun lọ, Ahinoamu ara Jesreeli, ati Abigaili
aya Nabali ara Karmeli.
6 Dafidi si banujẹ gidigidi, nitoripe awọn
enia na si nsọ̀rọ lati sọ ọ li okuta, nitoriti
inu gbogbo awọn enia na si bajẹ, oluku-

Digitized by Google

luku, ọkọnrin nitori ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, ati
nitori ọmọ rẹ̀ obirin: ṣugbọn Dafidi mu
ara rẹ̀ li ọkàn le ninu Oluwa Ọlọrun rẹ̀.
7 Dafidi si wi fun Abiatari alufa, ọmọ
Ahimeleki pe, emi bẹ̀ ọ, mu efodu fun mi
wá nihinyi. Abiatari si mu efodu na wá
fun Dafidi.
8 Dafidi si bere lọdọ Oluwa wipe, Ki
emi ki o lepa ogun yi bi? emi le ba wọn?
O si da a lohùn pe, Lepa: nitoripe ni biba
iwọ o ba wọn, ni gbígba iwọ o si ri wọn
gbà.
9 Bẹni Dafidi ati ẹgbẹta ọmọkọnrin ti
mbẹ lọdọ rẹ̀ si lọ, nwọn si wá si ibi odo
Besori, apakan si duro.
10 Ṣugbọn Dafidi ati irinwo ọmọkọnrin
lepa wọn: igba enia ti ãrẹ̀ mu, ti nwọn kò
le kọja odo Besori si duro lẹhin.
11 Nwọn si ri ara Egipti kan li oko,
nwọn si mu u tọ̀ Dafidi wá, nwọn si fun
u li onjẹ, o si jẹ; nwọn si fun u li omi
mu;
12 Nwọn si bùn u li akara eso ọpọtọ ati
ṣiri ajara gbigbẹ meji: nigbati o si jẹ ẹ
tan, ẹmi rẹ̀ si sọji: nitoripe ko jẹ onjẹ,
bẹ̃ni kò si mu omi ni ijọ mẹta li ọsan, ati
li oru.
13 Dafidi si bi i lere pe, Ọmọ tani iwọ
iṣe? ati nibo ni iwọ ti wá? On si wipe,
ọmọ ara Egipti li emi iṣe, ọmọ-ọdọ ọkọnrin
kan ara Amaleki; oluwa mi si fi mi silẹ,
nitoripe lati ijọ mẹta li emi ti ṣe aisan.
14 Awa si gbe ogun lọ siha gusun ti ara
Keriti, ati si apa ti iṣe ti Juda, ati si iha
gusun ti Kelebu; awa si kun Siklagi.
15 Dafidi si bi i lere pe, Iwọ le mu mi
sọkalẹ tọ̀ ẹgbẹ ogun yi lọ bi? On si
wipe, Fi Ọlọrun bura fun mi, pe, iwọ kì
yio pa mi, bẹ̃ni iwọ kì yio si fi mi le oluwa
mi lọwọ; emi o si mu ọ sọkalẹ tọ̀ ẹgbẹ
ogun na lọ.
16 O si mu u sọkalẹ, si wõ, nwọn si
tànka ilẹ, nwọn njẹ, nwọn nmu, nwọn si
njo, nitori ikogun pupọ ti nwọn ko lati ilẹ
awọn Filistini wá, ati lati ilẹ Juda.
17 Dafidi si pa wọn lati afẹmọjumọ titi
o fi di aṣalẹ ijọ keji: kò si si ẹnikan ti o là
ninu wọn, bikoṣe irinwo ọmọkọnrin ti nwọn
gun ibakasiẹ ti nwọn si sa.
18 Dafidi si gba gbogbo nkan ti awọn
ara Amaleki ti ko: Dafidi si gbà awọn
obirin rẹ̀ mejeji.
19 Kò si si nkan ti o kù fun wọn, kekere
tabi nla, ọmọkọnrin tabi ọmọbirin, tabi
ikogun, tabi gbogbo nkan ti nwọn ti ko:
Dafidi si gbà gbogbo wọn.
20 Dafidi si ko gbogbo agutan, ati malu,
nwọn si dà wọn ṣaju nkan miran ti nwọn
gbà, nwọn si wipe, Eyiyi ni ikogun ti
Dafidi.
21 Dafidi si ba igba ọkọnrin ti o ti rẹ̀ jù
ati tọ̀ Dafidi lẹhin, ti on ti fi silẹ li odò
Besori: nwọn si lọ ipade Dafidi, ati lati
pade awọn enia ti o pẹlu rẹ̀: Dafidi si pade
awọn enia na, o si ki wọn.
22 Gbogbo awọn enia buburu ati awọn
ọmọ Beliali ninu awọn ti o ba Dafidi lọ si
dahun, nwọn si wipe, Bi nwọn kò ti ba wa
lọ, awa kì yio fi nkan kan fun wọn ninu
ikogun ti awa rí gbà bikoṣe obirin oluku-
luku wọn, ati ọmọ wọn; ki nwọn ki o si
mu wọn, ki nwọn si ma lọ.
23 Dafidi si wipe, Ẹ má ṣe bẹ̃, enyin ará
mi: Oluwa li o fi nkan yi fun wa, on li o
si pa wa mọ, on li o si fi ẹgbẹ-ogun ti o
dide si wa le wa lọwọ.
24 Tani yio gbọ́ ti nyin ninu ọ̀ran yi?
ṣugbọn bi ipin ẹniti o sọkalẹ lọ si ìja ti ri,
bẹ̃ni ipin ẹniti o duro ti ẹrù; nwọn o si pin
i bakanna.
25 Lati ọjọ na lọ, o si pa a li aṣẹ, o si sọ
ọ li ofin fun Israeli titi di oni yi.
26 Dafidi si bọ̀ si Siklagi, o si rán ninu
ikogun na si awọn agbà Juda, ati si awọn
ọrẹ́ rẹ̀, o si wipe, Wõ, eyi li ẹ̀bun fun
nyin, lati inu ikogun awọn ọta Oluwa wá.
27 O si rán a si awọn ti o wà ni Beteli
ati si awọn ti o wà ni gusun Ramoti, ati si
awọn ti o wà ni Jattiri.
28 Ati si awọn ti o wà ni Aroeri, ati si
awọn ti o wà ni Sifmoti, ati si awọn ti o wà
ni Ẹstemoa.
29 Ati si awọn ti o wà ni Rakali, ati si
awọn ti o wà ni ilu awọn Jerameeli, ati si
awọn ti o wà ni ilu awọn ara Keni,
30 Ati si awọn ti o wà ni Horma, ati si
awọn ti o wà ni Koraṣani, ati si awọn ti o
wà ni Ataki.
31 Ati si awọn ti o wà ni Hebroni, ati si
gbogbo ilu wọnni ti Dafidi tikararẹ̀ ati
awọn ọmọkọnrin rẹ̀ ima rin kiri.

## ORI 31.

AWỌN Filistini si ba Israeli jà: awọn
ọkọnrin Israeli si sa niwaju awọn Fi-
listini, awọn ti o fi ara pa si ṣubu li oke
Gilboa.
2 Awọn Filistini si nlepa Saulu ati awọn
ọmọ rẹ̀ kikan; awọn Filistini si pa Jona-
tani, ati Abinadabu, ati Melkiṣua, awọn
ọmọ Saulu.
3 Inà ja si buru fun Saulu gidigidi, awọn

Digitized by Google

tafàtafa si ta a li ọfà, o si fi ara pa pupọ li
ọwọ́ awọn tafàtafa.
4 Saulu si wi fun ẹniti o rù ihamọra rẹ̀
pe, Fa ìda rẹ yọ, ki o si fi i gún mi, ki
awọn alaikọla wọnyi ki o má bà wá gún
mi, ati ki wọn ki o má ba fi mi ṣe ẹlẹya.
Ṣugbọn ẹniti o ru ihamọra rẹ̀ ko fẹ ṣe bẽ,
nitoripe ẹrù ba a gidigidi. Saulu si mu
idà na o si fi pa ara rẹ̀.
5 Nigbati ẹniti o rù ihamọra rẹ̀ si ri pe
Saulu kú, on na si fi idà rẹ̀ pa ara rẹ̀, o si
kú pẹlu rẹ̀.
6 Saulu si kú, ati awọn ọmọ rẹ̀ mẹta, ati
ẹni ti o rù ihamọra rẹ̀, ati gbogbo awọn
ọmọkọnrin rẹ̀ li ọjọ kanna.
7 Nigbati awọn ọkọnrin Israeli ti o wà
li apa keji afonifoji na, ati awọn ẹniti o wà
li apa keji Jordani, ri pe awọn ọkọnrin
Israeli sa, ati pe Saulu ati awọn ọmọbibi
rẹ̀ si kú, nwọn si fi ilu silẹ, nwọn si sa;
awọn Filistini si wá, nwọn si joko si ilu wọn.
8 O si ṣe, li ọjọ keji, nigbati awọn Filis-
tini de lati bọ́ nkan ti mbẹ lara awọn ti o
kú, nwọn si ri pe, Saulu ati awọn ọmọ rẹ̀
mẹta ṣubu li oke Gilboa,
9 Nwọn si ke ori rẹ̀, nwọn si bọ́ ihamọra
rẹ̀, nwọn si ranṣẹ lọ si ilẹ Filistini ka kiri,
lati ma sọ ọ nigbangba ni ile oriṣa wọn, ati
larin awọn enia.
10 Nwọn si fi ihamọra rẹ̀ si ile Aṣtaroti:
nwọn si kàn okú rẹ̀ mọ odi Betṣani.
11 Nigbati awọn ara Jabeṣi-Gileadi si
gbọ́ eyiti awọn Filistini ṣe si Saulu;
12 Gbogbo awọn ọkọnrin alagbara si dide,
nwọn si fi gbogbo oru na rìn, nwọn si gbe
okú Saulu, ati okú awọn ọmọbibi rẹ̀ kuro
lara odi Betṣani, nwọn si wá si Jabeṣi,
nwọn si sun wọn nibẹ.
13 Nwọn si ko egungun wọn, nwọn si
sin wọn li abẹ igi kan ni Jabeṣi, nwọn si
gbawẹ ni ijọ meje.

---

IWE KEJI TI

# SAMUELI.

## ORI 1.

O SI ṣe, lẹhin ikú Saulu, Dafidi si ti ibi
iparum awọn ara Amaleki bọ̀, Dafidi
si joko nijọ meji ni Siklagi;
2 O si ṣe ni ijọ kẹta, si wõ, ọkọnrin kan
si ti ibudo wá lati ọdọ Saulu; aṣọ rẹ̀ si
faya, erupẹ si mbẹ li ori rẹ̀: o si ṣe, nigbati
on si de ọdọ Dafidi, o wolẹ, o si tẹriba.
3 Dafidi si bi i lere pe, Nibo ni iwọ ti
wá? o si wi fun u pe, Lati ibudo Israeli li
emi ti sa wá.
4 Dafidi si tun bi lere wipe, Ọràn na ti
ri? emi bẹ ọ, sọ fun mi. On si dahun pe,
Awọn enia na sa loju ijà, ọ̀pọlọpọ ninu
awọn enia na pẹlu si ṣubu; nwọn si kú,
Saulu ati Jonatani ọmọ rẹ̀ si kú pẹlu.
5 Dafidi si bi ọmọdekọnrin na ti o sọ
fun u lere pe, Iwọ ti ṣe mọ̀ pe, Saulu ati
Jonatani ọmọ rẹ̀ kú?
6 Ọmọdekọnrin na ti o sọ fun u wipe,
Bi emi ti ṣe alabapade lori oke Gilboa, si
wõ, Saulu fi ara tì ọkọ̀ rẹ̀, si wõ, kẹkẹ́ ati
ẹlẹṣin nlepa rẹ̀ kikan.
7 Nigbati o si yi oju wo ẹhin rẹ̀, ti o si
ri mi, o pè mi, Emi si da a lohùn pe, Emi nĩ.
8 On si bi mi pe, Iwọ tani? Emi si da
a lohùn pe, ara Amaleki li emi.
9 On si tun wi fun mi pe, Duro le mi,
emi bẹ ọ ki o si pa mi: nitoriti wahala ba
mi, ẹmi mi si wà sibẹ.
10 Emi si duro le e, mo si pa a, nitori ti
o da mi loju pe, kò si tun le là mọ lẹhin
igbati o ti ṣubu: emi si mu ade ti o wà li
ori rẹ̀, ati ibọwọ ti o mbẹ li apa rẹ̀, emi si
mu wọn wá ihinyi sọdọ oluwa mi.
11 Dafidi si di aṣọ rẹ̀ mu, o si fà wọn ya,
gbogbo awọn ọkọnrin ti o wà lọdọ rẹ̀ si ṣe
bẽ gẹgẹ.
12 Nwọn si ṣọfọ, nwọn si sọkun, nwọn si
gbawẹ titi di aṣalẹ fun Saulu, ati fun Jona-
tani ọmọ rẹ̀, ati fun awọn enia Oluwa, ati
fun ile Israeli; nitoripe nwọn ti ipa idà
ṣubu.

Digitized by Google

13 Dafidi si bi ọmọdekọnrin na ti o rò
fun u wipe, Nibo ni iwọ ti wá? On si da
a li ohùn pe, Ọmọ alejo kan, ara Amaleki
li emi iṣe.
14 Dafidi si wi fun u pe, E ti ri ti iwọ
kò fi bẹ̀ru lati nà ọwọ́ rẹ lati fi pa ẹni-àmi-
ororo Oluwa.
15 Dafidi si pe ọkan ninu awọn ọmọde-
kọnrin, o si wipe, Sunmọ ọ, ki o si kọ lu
u. O si kọ lu u, on si kú.
16 Dafidi si wi fun u pe Ẹjẹ rẹ mbẹ li
ori ara rẹ; nitoripe ẹnu rẹ li o fi jẹwọ pe,
Emi li o pa ẹni àmi-ororo Oluwa.
17 Dafidi si fi orin ọ̀fọ yi ṣọ̀fọ̀ lori Saulu
ati lori Jonatani ọmọ rẹ̀:
18 O si pa aṣẹ lati kọ́ awọn ọmọ Juda ni
ilò ọrun: wõ, a ti kọ ọ sinu iwe Jaṣeri.
19 Ẹwà rẹ Israeli li a pa li oke giga rẹ:
wò bi awọn alagbara ti ṣubu!
20 Ẹ máṣe sọ ọ ni Gati, ẹ má si se koki-
ki rẹ̀ ni igboro Aṣkeloni; ki awọn ọmọbirin
Filistini ki o má ba yọ̀, ki ọmọbirin awọn
alaikọla ki o má ba yọ̀.
21 Ẹnyin oke Gilboa, ki ìri ki o má si,
ati ki ojò ki o má rọ̀ si nyin, ki ẹ má si ni
oko ọrẹ ẹbọ: nitori nibẹ li a gbe sọ asà
awọn alagbara nu, asà Saulu, bi ẹnipe a ko
fi ororo yàn a.
22 Ọrun Jonatani ki ipada, ati idà
Saulu ki ipada lasan lai kan ẹjẹ awọn ti a
pa, ati ọra awọn alagbara.
23 Saulu ati Jonatani ni ifẹni si ara
wọn, nwọn si dùn li ọjọ aiye wọn, ati ni
ikú wọn, nwọn kò ya ara wọn; nwọn yara
ju idì lọ, nwọn si li agbara ju kiniun lọ.
24 Ẹnyin ọmọbirin Israeli, ẹ sọkun lori
Saulu, ti o fi aṣọ òdodó ati ohun ọṣọ́ wọ̀
nyin, ti o fi ohun ọṣọ́ wura si ara aṣọ nyin.
25 Wo bi awọn alagbara ti ṣubu larin
ogun! A Jonatani! iwọ ti a pa li oke
giga rẹ!
26 Wahala ba mi nitori rẹ, Jonatani,
arakọnrin mi: didùn jọjọ ni iwọ jẹ fun mi:
ifẹ rẹ si mi jasi iyanu, o jù ifẹ obirin lọ.
27 Wo bi awọn alagbara ti ṣubu, ati bi
ohun ija ti ṣegbe!

## ORI 2.

O SI ṣe lẹhin eyi, Dafidi si bere lọwọ
Oluwa, pe, Ki emi ki o goke lọ si
ọkan ni ilu Juda wọnni bi? Oluwa si wi
fun u pe, Goke lọ: Dafidi si wipe, Niha
ibo ni ki emi ki o lọ? On si wipe, Ni
Hebroni.
2 Dafidi si goke lọ si ibẹ ati awọn obirin
rẹ̀ mejeji pẹlu, Ahinoamu ara Jesreeli ati
Abigaili obirin Nabali ara Karmeli.
3 Dafidi si mu awọn ọmọkọnrin rẹ̀ ti o
wà lọdọ rẹ̀ goke, olukuluku ton ti ara ile
rẹ̀: nwọn si joko ni ilu Hebroni wọnni.
4 Awọn ọkọnrin Juda si wá, nwọn si fi
Dafidi jọba nibẹ lori ile Juda. Nwọn si sọ
fun Dafidi pe, Awọn ọkọnrin Jabeṣi Gileadi
li o sinkú Saulu.
5 Dafidi si ran onṣẹ si awọn ọkọnrin
Jabeṣi-Gileadi o si wi fun wọn pe, Alabukun
fun li ẹnyin lati ọwọ́ Oluwa wá, bi ẹnyin
ti ṣe ore yi si oluwa nyin, si Saulu, ani ti ẹ
fi sinkú rẹ̀.
6 Njẹ ki Oluwa ki o ṣe ore ati otitọ fun
nyin: emi na yio si san ore yi fun nyin,
nitori ti ẹnyin ṣe nkan yi.
7 Njẹ ẹ si mu ọwọ́ nyin le, ki ẹ si jẹ
ẹni-alagbara: nitoripe Saulu oluwa nyin ti
kú, ile Juda si ti fi àmi-ororo yàn mi li ọba
wọn.
8 Ṣugbọn Abneri ọmọ Neri olori ogun
Saulu si mu Iṣboṣeti ọmọ Saulu, o si mu u
kọja si Mahanaimu;
9 On si fi i jọba lori Gileadi, ati lori
awọn ọmọ Aṣuri, ati lori Jesreeli, ati lori
Efraimu, ati lori Benjamini, ati lori gbogbo
Israeli.
10 Iṣboṣeti ọmọ Saulu si jẹ ẹni ogoji
ọdun nigbati o bẹrẹ si ijọba lori Israeli, o
si jọba li ọdun meji. Ṣugbọn idile Juda
ntọ Dafidi lẹhin.
11 Gbogbo ọjọ ti Dafidi fi jọba ni He-
broni lori ile Juda jẹ ọdun meje pẹlu oṣù
mẹfa.
12 Abneri ọmọ Neri, ati awọn iranṣẹ
Iṣboṣeti ọmọ Saulu si jade kuro ni Maha-
naimu lọ si Gibeoni.
13 Joabu ọmọ Seruia, ati awọn iranṣẹ
Dafidi si jade, nwọn si jọ pade nibi adagun
Gibeoni: nwọn si joko, ẹgbẹ kan li apa
ihin adagun, ẹgbẹ keji li apa keji adagun.
14 Abneri si wi fun Joabu pe, Jẹ ki
awọn ọmọkọnrin dide nisisiyi, ki nwọn ki
o si ta pero niwaju wa. Joabu si wipe, Jẹ
ki wọn ki o dide.
15 Nigbana li awọn mejila ninu ẹya
Benjamini ti iṣe ti Iṣboṣeti ọmọ Saulu dide,
nwọn si kọja siha keji; mejila ninu awọn
ọmọ Dafidi si dide.
16 Olukuluku wọn si di ọmọnikeji rẹ̀ li
ori mu, olukuluku si tẹ idà rẹ̀ bọ ẹnikeji
rẹ̀ ni ihà: nwọn si jọ ṣubu lulẹ: nitorina
li a si ṣe npe orukọ ibẹ na ni Helkatihas-
surimu, ti o wà ni Gibeoni.
17 Ijà na si kan gidigidi ni ijọ na, a si

Digitized by Google

le Abneri ati awọn ọkọnrin Israeli niwaju
awọn ọmọ Dafidi.
18 Awọn ọmọ Seruia mẹtẹta si mbẹ nibẹ,
Joabu, Abişai, ati Asaheli: ẹsẹ Asaheli si
fẹrẹ bi ẹsẹ agbọnrin ti o wà ni pápa.
19 Asaheli si nlepa Abneri; bi on ti nlọ
kò si yipada si ọwọ ọtun, tabi si ọwọ́ osì
lati ma tọ̀ Abneri lẹhin.
20 Nigbana ni Abneri boju wo ẹhin rẹ̀,
o si bere pe, Iwọ Asaheli ni? On si dahùn
pe, Emi ni.
21 Abneri si wi fun u pe, Iwọ yipada si
apakan si ọwọ́ ọtun rẹ, tabi si osì rẹ, ki
iwọ ki o si di ọkan mu ninu awọn ọmọkọn-
rin, ki o si mu ihamọra rẹ̀. Şugbọn Asa-
heli kọ̀ lati pada lẹhin rẹ̀.
22 Abneri si tun wi fun Asaheli pe, Pada
lẹhin mi, ẽşe ti emi o fi lu ọ bolẹ? bawo li
emi o ti şe gbe oju soke si Joabu arakọnrin
rẹ̀?
23 Şugbọn o si kọ̀ lati pada: Abneri si
fi òdi ọ̀kọ gun u labẹ inu, ọ̀kọ na si jade li
ẹhin rẹ̀: on si şubu lulẹ nibẹ, o si kú ni ibi
kanna; o si şe, gbogbo enia ti o de ibiti
Asaheli gbe şubu si, ti o si kú, si duro jẹ.
24 Joabu ati Abişai si lepa Abneri:
õrun si wọ̀, nwọn si de oke ti Amma ti o
wà niwaju Gia li ọ̀na iju Gibeoni.
25 Awọn ọmọ Benjamìni si ko ara wọn
jọ nwọn tẹle Abneri, nwọn si wa di ẹgbẹ
kan, nwọn si duro lori oke kan.
26 Abneri si pe Joabu, o si bi i lere pe,
Idà yio ma parun titi lailai bi? njẹ iwọ
kò iti mọ̀ pe yio koro nikẹhin? njẹ yio ha
ti pẹ to ki iwọ ki o to sọ fun awọn enia na,
ki nwọn ki o dẹkun lati ma lepa ará wọn?
27 Joabu si wipe, Bi Ọlọrun ti mbẹ,
bikoşe bi iwọ ti wi, nitotọ, li owurọ̀ li
awọn enia na iba ti goke lọ, olukuluku iba
ti pada lẹhin arakọnrin rẹ̀.
28 Joabu si fún ipè, gbogbo enia si duro
jẹ, nwọn kò si lepa Israeli mọ, bẽni nwọn
kò si tun jà mọ.
29 Abneri ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si fi
gbogbo oru na rìn ni pẹtẹlẹ, nwọn si kọja
Jordani, nwọn si rìn ni gbogbo Bitroni,
nwọn si wá si Mahanaimu.
30 Joabu si dẹkun ati ma tọ Abneri
lẹhin: o si ko gbogbo awọn enia na jọ,
enia mọkandi-logun li o kú pẹlu Asaheli
ninu awọn iranşẹ Dafidi.
31 Şugbọn awọn iranşẹ Dafidi si lù bolẹ
ninu awọn enia Benjamini; ati ninu awọn
ọmọkọnrin Abneri; ojì-di-ni-irin-wo enia
li o kú.
32 Nwọn si gbe Asaheli, nwọn si sin i
sinu ibojì baba rẹ̀ ti o wà ni Betlehemu.
Joabu ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ fi gbogbo oru
na rin, ilẹ si mọ́ wọn si Hebroni.

## ORI 3.

OGUN na si pẹ titi larin idile Saulu ati
idile Dafidi: agbara Dafidi si npọ̀ si
i, şugbọn idile Saulu nrẹ̀hin sì.
2 Dafidi si bi ọmọkọnrin ni Hebroni:
Ammoni li akọbi rẹ̀ ti Ahinoamu ara
Jesreeli bi fun u.
3 Ekeji rẹ̀ si ni Kileabu, ti Abigaili aya
Nabali ara Karmeli nì bi fun u; ẹkẹta si
ni Absalomu ọmọ ti Maaka ọmọbirin Tal-
mai ọba Geşuri bi fun u.
4 Ẹkẹrin si ni Adonija ọmọ Haggiti;
ati ikarun ni Şefatia ọmọ Abitali;
5 Ẹkẹfa si ni Itreamu, ti Egla aya Dafidi
bi fun u. Wọnyi li a bi fun Dafidi ni
Hebroni.
6 O si şe, nigbati ogun wà larin idile
Saulu ati idile Dafidi, Abneri si di alagbara
ni idile Saulu.
7 Saulu ti ni àle kan, orukọ rẹ̀ si njẹ
Rispa, ọmọbirin Aia: Işboşeti si bi Abneri
lere pe, Eşe ti iwọ fi wọle tọ àle baba
mi lọ?
8 Abneri si binu gidigidi nitori ọ̀rọ
wọnyi ti Işboşeti sọ fun u, o si wipe, Emi
işe ori aja bi? emi ti mo mba Juda jà, ti
mo si şanu loni fun idile Saulu baba rẹ,
ati fun ará rẹ̀, ati awọn ọrẹ rẹ̀, ti emi kò si
fi iwọ le Dafidi lọwọ, iwọ si ka ẹ̀şẹ si mi
lọrùn nitori obirin yi loni?
9 Bẽni ki Ọlọrun ki o şe si Abneri, ati
jù bẹ̃ lọ pẹlu, bi Oluwa ti bura fun Dafidi,
bi emi kò ni şe bẹ fun u.
10 Lati mu ijọba na kuro ni idile Saulu,
ati lati gbe itẹ Dafidi kalẹ lori Israeli, ati
lori Juda, lati Dani titi o fi de Beerşeba.
11 On kò si le da Abneri lohùn kan
nitoriti o bẹ̀ru rẹ̀.
12 Abneri si ran awọn onşẹ si Dafidi
nitori rẹ̀, wipe, Ti tani ilẹ na işe? ati pe,
Ba mi şe adehun, si wõ, ọwọ́ mi o wà pẹlu
rẹ, lati yi gbogbo Israeli sọdọ rẹ.
13 On si wi pe, O dara, emi o ba ọ şe
adehun: şugbọn nkan kan li emi o bere
lọwọ rẹ, eyini ni, Iwọ ki yio ri oju mi, afi
bi iwọ ba mu Mikali ọmọbirin Saulu wá,
nigbati iwọ ba mbọ, lati ri oju mi.
14 Dafidi si ran awọn iranşẹ si Işboşeti
ọmọ Saulu pe, Fi Mikali obirin mi le mi
lọwọ, ẹniti emi ti fi ọgọrun ẹfa abẹ awọn
Filistini fẹ.

Digitized by Google

15 Işboşeti si ranşẹ, o si gbà a lọwọ
ọkọnrin ti a npè ni Faltieli ọmọ Laişi.
16 Ọkọ rẹ̀ si mba a lọ, o nrin, o si
nsọkun lẹhin rẹ̀ titi o fi de Bahurimu.
Abneri si wi fun u pe, Pada lọ. On si
pada.
17 Abneri si ba awọn agbà Israeli sọ̀rọ,
pe, Ẹnyin ti nşe afẹri Dafidi ni igbà atijọ,
lati jọba lori nyin.
18 Njẹ, ẹ şe e: nitoriti Oluwa ti sọ fun
Dafidi pe, Lati ọwọ́ Dafidi iranşẹ mi li emi
o gbà Israeli enia mi là kuro lọwọ awọn
Filistini ati lọwọ gbogbo awọn ọta wọn.
19 Abneri si wi leti Benjamini: Abneri
si lọ isọ leti Dafidi ni Hebroni gbogbo
eyiti o dara loju Israeli, ati loju gbogbo ilẹ
Benjamini.
20 Abneri si tọ̀ Dafidi wá ni Hebroni,
ogún ọmọkọnrin si pẹlu rẹ̀. Dafidi si se
ase fun Abneri ati fun awọn ọmọkọnrin ti
o wà pẹlu rẹ̀.
21 Abneri si wi fun Dafidi pe, Emi o
dide, emi o si lọ, emi o si ko gbogbo Israeli
jọ sọdọ ọba oluwa mi, nwọn o si ba ọ şe
adehun, iwọ o si jọba gbogbo wọn bi ọkàn
rẹ ti nfẹ. Dafidi si rán Abneri lọ; on si
lọ li alafia.
22 Si wõ, awọn iranşẹ Dafidi ati Joabu
si ti ibi ilepa ẹgbẹ ogun kan bọ̀, nwọn si
mu ikogun pupọ bọ̀; şugbọn Abneri kò si
lọdọ Dafidi ni Hebroni; nitoriti on ti rán
a lọ: on si ti lọ li alafia.
23 Nigbati Joabu ati gbogbo ogun ti o
pẹlu rẹ̀ si de, nwọn si sọ fun Joabu pe,
Abneri, ọmọ Neri ti tọ̀ ọba wá, on si ti rán
a lọ, o si ti lọ li alafia.
24 Joabu si tọ̀ ọba wá, o si wipe, Kini
iwọ şe nì? wõ, Abneri tọ̀ ọ wá; ehatişe ti
iwọ si fi rán a lọ? on si ti lọ.
25 Iwọ mọ̀ Abneri ọmọ Neri, pe, o wá
lati tàn ọ jẹ, ati lati mọ̀ ijadelọ rẹ, ati
ibọsile rẹ, ati lati mọ̀ gbogbo eyi ti iwọ
nşe.
26 Nigbati Joabu si jade kuro lọdọ Da-
fidi, o si ran awọn iranşẹ lepa Abneri, nwọn
si pè e pada lati ibi kanga Sira: Dafidi kò
si mọ̀.
27 Abneri si pada si Hebroni, Joabu si
ba a tẹ̀ larin oju ọna lati ba a sọ̀rọ li alafia,
o si gún u nibẹ labẹ inu, o si kú, nitori ẹjẹ
Asaheli arakọnrin rẹ̀.
28 Lẹhin igbati Dafidi si gbọ́ ọ, o si
wipe, emi ati ijọba mi si jẹ alaişẹ niwaju
Oluwa titi lai ni ẹjẹ Abneri ọmọ Neri:
29 Jẹ ki o wà li ori Joabu, ati li ori
gbogbo idile baba rẹ̀; ki a má si fẹ ẹni ti
o li arùn isun, tabi adẹtẹ, tabi ẹni ti ntẹ̀
ọpá, tabi, ẹniti a o fi idà pa, tabi ẹniti o
şe alaili onjẹ kù ni ile Joabu.
30 Joabu ati Abişai arakọnrin rẹ̀ si pa
Abneri, nitoripe on ti pa Asaheli arakọnrin
wọn ni Gibeoni li ogun.
31 Dafidi si wi fun Joabu ati fun gbogbo
enia ti mbẹ lọdọ rẹ̀ pe, Ẹ fa aşọ nyin ya,
ki ẹnyin ki o si mu aşọ-ọ̀fọ, ki ẹnyin ki o
si sọkun niwaju Abneri. Dafidi ọba tika-
rarẹ̀ si tẹle posi rẹ̀.
32 Nwọn si sin Abneri ni Hebroni: ọba
si gbe ohùn rẹ̀ soke, o si sọkun ni iboji
Abneri; gbogbo awọn enia na si sọkun.
33 Ọba si sọkun lori Abneri, o si wipe,
Abneri iba ku iku aşiwere?
34 A kò sa dè ọ li ọwọ́, bẽ li a kò si kàn
ẹsẹ rẹ li abà: gẹgẹ bi enia iti şubu niwaju
awọn ikà enia, bẽni iwọ şubu. Gbogbo
awọn enia na si tun sọkun lori rẹ̀.
35 Nigbati gbogbo enia si wá lati gbà
Dafidi ni iyanju ki o jẹun nigbati ọjọ si
mbẹ, Dafidi si bura wipe, Bẽni ki Ọlọrun
ki o şe si mi, ati ju bẽ lọ, bi emi ba tọ onjẹ
wò, tabi nkan miran, titi õrun yio fi wọ̀.
36 Gbogbo awọn enia si kiyesi i, o si
dara loju wọn: gbogbo eyi ti ọba şe si dara
loju gbogbo awọn enia na.
37 Gbogbo awọn enia na ati gbogbo
Israeli si mọ̀ lọjọ na pe, ki işe ifẹ ọba lati
pa Abneri ọmọ Neri.
38 Ọba si wi fun awọn iranşẹ rẹ̀ pe,
Ẹnyin kò mọ̀ pe olori ati ẹni-nla kan li o
şubu li oni ni Israeli?
39 Emi si şe alailagbara loni, bi o tilẹ
jẹ pe a fi emi jọba; awọn ọkọnrin wọnyi
ọmọ Seruia si le jù mi lọ: Oluwa ni yio
san a fun ẹni ti o se ibi gẹgẹ bi iwa buburu
rẹ̀.

## ORI 4.

NIGBATI ọmọ Saulu si gbọ́ pe Abneri
kú ni Hebroni, ọwọ́ rẹ̀ si rọ, gbogbo
Israeli si rẹ̀wẹsi.
2 Ọmọ Saulu si ni ọkọnrin meji ti işe
olori ẹgbẹ ogun: a npe orukọ ọkan ni
Baana, ati orukọ keji ni Rekabu, awọn
ọmọ Rimmoni ara Beeroti ti awọn ọmọ
Benjamini: (nitoripe a si ka Beeroti pẹlu
Benjamini:
3 Awọn ara Beeroti si ti sa lọ si Gittai-
mu, nwọn si şe atipo nibẹ titi o fi di ọjọ
oni yi.)
4 Jonatani ọmọ Saulu si ti bi ọmọkọnrin
kan ti ẹsẹ rẹ̀ rọ. On si jẹ ọdun marun,
nigbati ihin de niti Saulu ati Jonatani lati

Digitized by Google

Jesreeli wá, olutọ́ rẹ̀ si gbe e, o si sa lọ: o
si ṣe, bi o si ti nyara lati sa lọ, on si ṣubu,
o si ya arọ. Ọrukọ rẹ̀ a ma jẹ Mefiboṣeti.
5 Awọn ọmọ Rimmoni, ara Beeroti,
Rekabu ati Baana si lọ, nwọn si wá si ile
Iṣboṣeti li ọsangangan, on si dubulẹ lori
ibusun kan li ọjọkanri.
6 Si wõ, nwọn si wá si arin ile na, nwọn
si ṣe bi ẹnipe nwọn nfẹ mu alikama; nwọn
si gun u labẹ inu: Rekabu ati Baana ara-
kọnrin rẹ̀ si sa lọ.
7 Nigbati nwọn wọ ile na lọ, on si dubulẹ
lori ibusun rẹ̀ ninu iyẹwu rẹ̀, nwọn si lu u
pa, nwọn si bẹ ẹ li ori, nwọn gbe ori rẹ̀,
nwọn si fi gbogbo oru rin ni pẹtẹlẹ na.
8 Nwọn si gbe ori Iṣboṣeti tọ̀ Dafidi wá
ni Hebroni, nwọn si wi fun ọba pe, Wõ,
ori Iṣboṣeti ọmọ Saulu ọta rẹ, ti o ti nwá
ẹmi rẹ kiri; Oluwa ti gbẹ̀san fun ọba
oluwa mi loni lara Saulu ati lara iru-ọmọ rẹ̀.
9 Dafidi si da Rekabu ati Baana ara-
kọnrin rẹ̀, awọn ọmọ Rimmoni ara Beeroti
lohùn, o si wi fun wọn pe, Bi Oluwa ti
mbẹ, ẹniti o gbà ẹmi mi lọwọ gbogbo ipọnju,
10 Nigbati ẹnikan rò fun mi pe, Wõ,
Saulu ti kú, li oju ara rẹ̀ on si jasi ẹni ti o mu
ihin rere wá, emi si mu u, mo si pa a ni
Siklagi, ẹniti o ṣebi on o ri nkan gbà nitori
ihin rere rẹ̀.
11 Melomelo ni, nigbati awọn ikà enia
pa olododo enia kan ni ile rẹ̀ lori ibusun
rẹ̀? njẹ emi ha si le ṣe alaibere ẹjẹ rẹ̀ lọwọ
nyin bi? ki emi si mu nyin kuro laiye?
12 Dafidi si fi aṣẹ fun awọn ọdọmọkon-
rin rẹ̀, nwọn si pa wọn, nwọn si ke ọwọ́ ati
ẹsẹ wọn, a si fi wọn ha lori igi ni Hebroni.
Ṣugbọn nwọn mu ori Iṣboṣeti, nwọn si sin
i ni iboji Abneri ni Hebroni.

## ORI 5.

GBOGBO ẹya Israeli si tọ̀ Dafidi wá ni
Hebroni, nwọn si wipe, Wõ, egungun
rẹ ati ẹran ara rẹ li awa iṣe.
2 Ati nigba atijọ, nigbati Saulu fi jọba
lori wa, iwọ li ẹniti ima ko Israeli jade,
iwọ ni si ma mu wọn bọ̀ wá ile: Oluwa si
wi fun ọ pe, Iwọ o bọ́ Israeli awọn enia mi,
iwọ o si jẹ olori fun Israeli.
3 Gbogbo agba Israeli si tọ ọba wá ni
Hebroni, Dafidi ọba si ba wọn ṣe adehun
kan ni Hebroni, niwaju Oluwa: nwọn si fi
ororo yan Dafidi li ọba Israeli.
4 Dafidi si jẹ ẹni ọgbọn ọdun nigbati o
jọba; on si jọba li ogoji ọdun.
5 O jọba ni Hebroni li ọdun meje on oṣu
mẹfa lori Juda: o si jọba ni Jerusalemu li
ọdun mẹtalelọgbọn lori gbogbo Israeli ati
Juda.
6 Ati ọba ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si lọ si
Jerusalemu sọdọ awọn ara Jebusi, awọn
enia ilẹ na: awọn ti o si ti wi fun Dafidi
pe, Bikoṣepe iwọ ba mu awọn afọju ati awọn
arọ kuro, iwọ ki yio wọ ihin wá: nwọn si
wipe, Dafidi ki yio lè wá sihin.
7 Ṣugbọn Dafidi si fi agbara gbà ilu odi
Sioni: eyi na ni iṣe ilu Dafidi.
8 Dafidi si sọ lọjọ na pe, Ẹnikẹni ti yio
kọlu awọn ara Jebusi, jẹ ki o gbà oju à-
gbàrá, ki o si kọlu awọn ayarọ ati awọn afọju
ti ọkàn Dafidi korira. Nitorina ni nwọn
ṣe wipe, Afọju ati arọ wà nibẹ, ki yio le
wọle.
9 Dafidi si joko ni ile awọn ọmọ-ogun ti
ti o ni odi, a si npè e ni ilu Dafidi. Da-
fidi mọ igànná yi i ka lati Millo wá, o si kọ
ile ninu rẹ̀.
10 Dafidi si npọ̀ si i, Oluwa Ọlọrun awọn
ọmọ-ogun si wà pẹlu rẹ.
11 Hiramu ọba Tire si rán awọn iranṣẹ si
Dafidi, ati igi kedari, ati awọn gbẹnàgbẹnà,
ati awọn ti ngbẹ́ okuta ogiri: nwọn si kọ́
ile kan fun Dafidi.
12 Dafidi si kiyesi i pe, Oluwa ti fi idi
on mulẹ lati jọba lori Israeli, ati pe, o gbe
ijọba rẹ̀ ga nitori Israeli awọn enia rẹ̀.
13 Dafidi si tun mu awọn alè ati aya si
i lati Jerusalemu wá, lẹhin igbati o ti He-
broni bọ̀: nwọn si bi ọmọkọnrin ati ọmọ-
birin fun Dafidi.
14 Eyi si ni orukọ awọn ti a bi fun u ni
Jerusalemu, Sammua ati Ṣobabu, ati Na-
tani, ati Solomoni,
15 Ati Ibehari, ati Eliṣua, ati Nefegi,
ati Jafia,
16 Ati Eliṣama, ati Eliada, ati Elifaleti,
17 Ṣugbọn nigbati awọn Filistini gbọ́ pe,
nwọn ti fi Dafidi jọba lori Israeli, gbogbo
awọn Filistini si goke wá lati wá Dafidi;
Dafidi si gbọ́, o si sọkalẹ lọ si ilu odi.
18 Awọn Filistini si wá, nwọn si tẹ́ ara
wọn li afonifoji Refaimu.
19 Dafidi si bere lọdọ Oluwa, pe, Ki emi
ki o goke tọ̀ awọn Filistini bi? iwọ o fi wọn
le mi lọwọ bi? Oluwa si wi fun Dafidi pe,
Goke lọ: nitoripe, dajudaju emi o fi awọn
Filistini le ọ lọwọ.
20 Dafidi si de Baal-perasimu, Dafidi si
pa wọn nibẹ, o si wipe, Oluwa ti ya lù
awọn ọtá mi niwaju mi, gẹgẹ bi omi iti ya.
Nitorina li on ṣe pe orukọ ibẹ na ni Baal-
perasimu.



Digitized by Google

21 Nwọn si fi orişa wọn silẹ nibẹ, Dafidi
ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si ko wọn.
22 Awọn Filistini si tún goke wá, nwọn
si tàn ara wọn kalẹ ni afonifoji Refaimu.
23 Dafidi si bere lọdọ Oluwa, on si wipe,
Máşe goke lọ; şugbọn bù wọn lẹhin, ki o
si kọlu wọn niwaju awọn igi Baka.
24 Yio si şe, nigbati iwọ ba gbọ́ iro ẹsẹ
lori awọn igi Baka na, nigbana ni iwọ o si
yara, nitoripe nigbana li Oluwa yio jade lọ
niwaju rẹ, lati kọlu ogun awọn Filistini.
25 Dafidi si şe bẹ̃, gẹgẹ bi Oluwa ti paşẹ
fun u; o si kọlu awọn Filistini lati Geba
titi iwọ o fi de Gaseri.

## ORI 6.

DAFIDI si tun ko gbogbo awọn akọni
ọkọnrin ni Israeli jọ, nwọn si jẹ ẹgbã
mẹ̃dogun.
2 Dafidi si dide, o si lọ, ati gbogbo awọn
enia ti mbẹ lọdọ rẹ̀, lati Baale ti Juda wá,
lati mu apoti-ẹri Ọlọrun ti ibẹ wá, eyi ti a
npè orukọ rẹ̀ ni orukọ Oluwa awọn ọmọ-
ogun ti o joko lãrin awọn Kerubu.
3 Nwọn si gbe apoti-ẹri Ọlọrun na gun
kẹkẹ́ titun kan, nwọn si mu u lati ile
Abinadabu wá, eyi ti o wà ni Gibea: Ussa
ati Ahio, awọn ọmọ Abinadabu si ndà kẹkẹ́
titun na.
4 Nwọn si mu u lati ile Abinadabu jade
wá, ti o wà ni Gibea, pẹlu apoti-ẹri Ọlọrun;
Ahio si nrìn niwaju apoti-ẹri na.
5 Dafidi ati gbogbo ile Israeli si şire
niwaju Oluwa lara gbogbo oniruru elò orin
ti a fi igi arere şe, ati lara duru, ati lara
psalteri, ati lara timbreli, ati lara korneti,
ati lara aro.
6 Nigbati nwọn si de ibi ipakà Nakoni,
Ussa si nà ọwọ́ rẹ̀ si apoti-ẹri Ọlọrun, o si
dì i mu, nitoriti malu kọsẹ.
7 Ibinu Oluwa si ru si Ussa; Ọlọrun si
pa a nibẹ nitori işişe rẹ̀; nibẹ li o si kú li
ẹba apoti-ẹri Ọlọrun.
8 Inu Dafidi si bajẹ nitoriti Oluwa ke
Ussa kuro: o si pe orukọ ibẹ na ni Peresi-
Ussa titi o fi di oni yi.
9 Dafidi si bẹru Oluwa ni ijọ nà, o si
wipe, Apoti-ẹri Oluwa yio ti şe tọ̀ mi wá?
10 Dafidi kò si fẹ mu apoti-ẹri Oluwa
sọdọ rẹ̀ si ilu Dafidi: şugbọn Dafidi si mu
u yà si ile Obedi-Edomu ara Gati.
11 Apoti-ẹri Oluwa si gbe ni ile Obedi-
Edomu ara Gati li oşu mẹta: Oluwa si
bukún fun Obedi-Edomu, ati gbogbo ile rẹ̀.
12 A si rò fun Dafidi ọba, pe, Oluwa ti
bukún fun ile Obedi-Edomu, ati gbogbo
eyi ti işẹ tirẹ̀, nitori apoti-ẹri Ọlọrun.
Dafidi si lọ, o si mu apoti-ẹri Ọlọrun na
goke lati ile Obedi-Edomu wá si ilu Dafidi
ton ti ayọ̀.
13 O si şe, nigbati awọn enia ti o rù
apoti-ẹri Oluwa ba si şi ẹsẹ mẹfa, on a si fi
malu ati ẹran abọpa rubọ.
14 Dafidi si fi gbogbo agbara rẹ̀ jó niwaju
Oluwa; Dafidi si wọ̀ efodu ọgbọ̀.
15 Bẹ̃ni Dafidi ati gbogbo ile Israeli si
gbe apoti-ẹri Oluwa goke wá, ti awọn ti iho
ayọ̀, ati pẹlu iro ipè.
16 Bi apoti-ẹri Oluwa si ti wọ̀ ilu Dafidi
wá; Mikali ọmọbirin Saulu si wò lati oju
ferese, o si ri Dafidi ọba nfò soke o si njo
niwaju Oluwa; on si kẹgàn rẹ̀ li ọkàn rẹ̀.
17 Nwọn si mu apoti-ẹri Oluwa na wá,
nwọn si gbe e kalẹ sipò rẹ̀ larin agọ na ti
Dafidi pa fun u: Dafidi si rubọ sisun ati
ẹbọ irẹpọ̀ niwaju Oluwa.
18 Dafidi si pari işẹ ẹbọ sisun ati ẹbọ
irẹpọ̀ na, o si sure fun awọn enia na li
orukọ Oluwa awon ọmọ-ogun.
19 O si pin fun gbogbo awọn enia na,
ani fun gbogbo ọpọ enia Israeli, ati ọkọnrin
ati obirin; fun olukuluku işu akara kan ati
ẹkirí ẹran kan, ati akara didun kan.
Gbogbo awọn enia na si tuka lọ, olukuluku
si ile rẹ̀.
20 Dafidi si yipada lati sure fun awọn
ara ile rẹ̀, Mikali ọmọbirin Saulu si jade
lati wa pade Dafidi, o si wipe, Bi o ti şe
ohun ogo to loni fun ọba Israeli, ti o bọ
ara rẹ̀ silẹ loni loju awọn iranşẹbirin awọn
iranşẹ rẹ̀, gẹgẹ bi ọkan ninu awọn enia asan
iti bọra rẹ̀ silẹ!
21 Dafidi si wi fun Mikali pe, Niwaju
Oluwa ni, ẹniti o yàn mi fẹ jù baba rẹ lọ,
ati ju gbogbo idile rẹ̀ lọ, lati fi emi şe olori
awọn enia Oluwa, ani lori Israeli, emi o si
şire niwaju Oluwa.
22 Emi o si tun rẹ̀ ara mi silẹ jù bẹ̃ lọ,
emi o si şe alainiyìn loju ara mi, ati loju
awọn iranşẹbirin wọnni ti iwọ wi, lọdọ wọn
na li emi o si li ogo.
23 Mikali ọmọbirin Saulu kò si bi ọmọ,
titi o fi di ọjọ ikú rẹ̀.

## ORI 7.

O SI şe, nigbati ọba si joko ni ile rẹ̀, ti
Oluwa si fun u ni isimi yika kiri kuro
lọwọ gbogbo awọn ọta rẹ̀,
2 Ọba si wi fun Natani woli pe Sa wõ,
emi ngbe inu ile ti a fi kedari kọ, şugbọn
apoti-ẹri Ọlọrun ngbe inu ibi ti a fi aşọ
ke.

Digitized by Google

3 Natani si wi fun ọba pẹ, Lọ, ki o si ṣe gbogbo eyi ti o wà li ọkàn rẹ, nitoripe Oluwa wà pẹlu rẹ.

4 O si ṣe li oru na ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Natani wá, pe,

5 Lọ, sọ fun iranṣẹ mi, fun Dafidi, pe, Bayi li Oluwa wi, iwọ o ha kọ ile fun mi ti emi o gbe?

6 Nitoripe, emi ko iti gbe inu ile kan lati ọjọ ti emi ti mu awọn ọmọ Israeli goke ti ilẹ Egipti wá, titi di oni yi, ṣugbọn emi ti nrin ninu agọ, ati ninu agberin.

7 Ni ibi gbogbo ti emi ti nrin larin gbogbo awọn ọmọ Israeli, emi ti iba ọkan ninu ẹya Israeli, ti emi pa aṣẹ fun lati ma bọ awọn enia mi ani Israeli sọ̀rọ pe, Ẽṣe ti ẹnyin kò fi kedari kọ ile fun mi?

8 Njẹ, nitorina, bayi ni iwọ o si wi fun iranṣẹ mi ani Dafidi pe, Bayi ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, emi ti mu iwọ kuro lati inu agbo agutan wá, lati mámà tẹle awọn agutan, mo si fi ọ jẹ olori awọn enia mi, ani Israeli.

9 Emi si wà pẹlu rẹ nibikibi ti iwọ nlọ, emi sa ke gbogbo awọn ọta rẹ kuro niwaju rẹ, emi si ti sọ orukọ rẹ di nla, gẹgẹ bi orukọ awọn enia nla ti o wà li aiye.

10 Emi o si yàn ibi kan fun awọn enia mi, ani Israeli, emi o si gbìn wọn, nwọn o si ma joko ni ibujoko ti wọn, nwọn kì yio si ṣipo pada mọ; awọn ọmọ enia buburu kì yio si pọn wọn loju mọ, bi igba atijọ.

11 Ati gẹgẹ bi akoko igba ti emi ti fi aṣẹ fun awọn onidajọ lori awọn enia mi, ani Israeli, emi fi isimi fun ọ lọwọ gbogbo awọn ọta rẹ. Oluwa si wi fun ọ pe, Oluwa yio kọ ile kan fun ọ.

12 Nigbati ọjọ rẹ ba pe, ti iwọ o si sùn pẹlu awọn baba rẹ, emi o si gbe iru-ọmọ rẹ leke lẹhin rẹ, eyi ti o ti inu rẹ jade wá, emi o si fi idi ijọba rẹ̀ kalẹ.

13 On o si kọ ile fun orukọ mi, emi o si fi idi itẹ ijọba rẹ̀ kalẹ lailai.

14 Emi o ma ṣe baba fun u, on o si ma jẹ ọmọ mi. Bi on ba dẹṣẹ, emi o si fi ọpá enia nà a, ati inà awọn ọmọ enia.

15 Ṣugbọn ãnu mi kì yio yipada kuro lọdọ rẹ̀, gẹgẹ bi emi ti mu u kuro lọdọ Saulu, ti emi ti mu kuro niwaju rẹ.

16 A o si fi idile rẹ ati ijọba rẹ mulẹ niwaju rẹ titi lai: a o si fi idi itẹ rẹ mulẹ titi lai.

17 Gẹgẹ bi gbogbo ọ̀rọ wọnyi, ati gẹgẹ bi gbogbo iran yi, bẽni Natani si sọ fun Dafidi.

18 Dafidi ọba si wọle lọ, o si duro niwaju Oluwa, o si wipe, Oluwa Ọlọrun? Tali emi, ati ki si ni idile mi, ti iwọ fi mu mi di isisiyi?

19 Nkan kekere li eyi sa jasi li oju rẹ, Oluwa Ọlọrun; iwọ si sọ ti idile iranṣẹ rẹ pẹlu ni ti akoko ti o jina. Eyi ha ṣe ìwa enia bi, Oluwa Ọlọrun?

20 Kini Dafidi iba si ma wi si i fun ọ? Iwọ, Oluwa Ọlọrun mọ̀ iranṣẹ rẹ.

21 Nitori ọ̀rọ rẹ, ati gẹgẹ bi ifẹ ọkàn rẹ, ni iwọ ṣe gbogbo nkan nla wọnyi, ki iranṣẹ rẹ ki o le mọ̀.

22 Iwọ si tobi, Oluwa Ọlọrun: kò si si ẹniti o dabi rẹ, kò si si Ọlọrun kan lẹhin rẹ, gẹgẹ bi gbogbo eyi ti awa fi eti wa gbọ́.

23 Orilẹ-ède kan wo li o si mbẹ li aiye ti o dabi awọn enia rẹ, ani Israeli, awọn ti Ọlorun lọ ràpada lati sọ wọn di enia rẹ̀, ati lati sọ wọn li orukọ, ati lati ṣe nkan nla fun nyin, ati nkan iyanu fun ilẹ rẹ, niwaju awọn enia rẹ, ti iwọ ti ràpada fun ara ı lati Egipti wá, ani awọn orilẹ-ède ati awọ. oriṣa wọn.

24 Iwọ si fi idi awọn enia rẹ, ani Israeli, kalẹ fun ara rẹ lati sọ wọn di enia rẹ titi lai: iwọ Oluwa si wa di Ọlọrun fun wọn.

25 Njẹ, Oluwa Ọlọrun, jẹ ki ọ̀rọ na ti iwọ sọ niti iranṣẹ rẹ, ati niti idile rẹ̀, ki o duro titi lai, ki o si ṣe bi iwọ ti wi.

26 Jẹ ki orukọ rẹ ki o ga titi lai, pe, Oluwa awọn ọmọ-ogun li Ọlọrun lori Israeli: si jẹ ki a fi idile Dafidi iranṣẹ rẹ mulẹ niwaju rẹ.

27 Nitoripe iwọ, Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli ti sọ li eti iranṣẹ rẹ, pe, emi o ṣe idile kan fun ọ: nitorina ni iranṣẹ rẹ si ṣe ni i li ọkàn rẹ̀ lati gbadura yi si ọ.

28 Njẹ, Oluwa Ọlọrun, iwọ li Ọlọrun na, ọrọ rẹ wọnni yio si jasi otitọ, iwọ si jẹ'jẹ nkan rere yi fun iranṣẹ rẹ:

29 Njẹ, jẹ ki o wù ọ lati bukún idile iranṣẹ rẹ, ki o wà titi lai niwaju rẹ: nitori iwọ, Oluwa Ọlọrun, li o ti sọ ọ: si jẹ ki ibukún ki o wà ni idile iranṣẹ rẹ titi lai, nipasẹ ibukún rẹ.

## ORI 8.

O SI ṣe, lẹhin eyi, Dafidi si kọlu awọn Filistini, o si tẹri wọn ba: Dafidi si gbà Metegamma lọwọ awọn Filistini.

2 O si kọlu Moabu, a si fi okùn tita kan diwọ̀n wọn, o si da wọn bu'lẹ; o si ṣe oṣuwọn okun meji ni iye awọn ti on o pa, ati

Digitized by Google

ękún oşuwọn okùn kan ni iye awọn ti yio
dá si. Awọn ara Moabu si nsìn Dafidi,
nwọn a si ma mu ębùn wá.
3 Dafidi si kọlu Hadadeseri ọmọ Reho-
bu, ọba Soba, bi on si ti nlọ lati gbà ilę rę̀
pada ti o gbè odo Eufrate.
4 Dafidi si gbà ęgbęrun kękę lọwọ rę̀,
ati ọ̀dęgbęrin ęlęşin, ati ęgbãwa awọn
ęlęsę: Dafidi si ja gbogbo ęşin kękę́ wọn
wọnni ni pátì, şugbọn o da ọgọrun kękę́ si
ninu wọn.
5 Nigbati awọn ara Siria ti Damasku si
wá lati ran Hadadeseri ọba Soba lọwọ,
Dafidi si pa ęgbãmọkanla enia ninu awọn
ara Siria.
6 Dafidi si fi awọn ologun si Siria ti
Damasku: awọn ara Siria si wa sìn Dafidi,
nwọn a si ma mu ębùn wá. Oluwa si pa
Dafidi mọ nibikibi ti o nlọ.
7 Dafidi si gbà asà wura ti o wà lara
awọn iranşę Hadadeseri, o si ko wọn wá si
Jerusalemu.
8 Lati Beta, ati lati Berotai, awọn ilú
Hadadeseri, ni Dafidi ọba si ko ọ̀pọlọpọ idę
wá.
9 Nigbati Toi ọba Hamati si gbọ́ pe Da-
fidi ti pa gbogbo ogun Hadadeseri,
10 Toi si ran Joramu ọmọ rę̀ si Dafidi
ọba, lati ki i, ati lati sure fun u, nitoripe o
ti ba Hadadeseri jagun, o si ti pa a: nito-
riti Hadadeseri sa ti ba Toi jagun. Joramu
si ni ohun elo fadaka, ati ohun elo wura,
ati ohun elo idę li ọwọ́ rę̀:
11 Dafidi ọba si fi wọn fun Oluwa, pęlu
fadaka, ati wura ti o ti yà si mimọ́, eyi ti
o ti gbà lọwọ awọn orilę-ède ti o ti şęgun;
12 Lọwọ Siria ati lọwọ Moabu, ati lọwọ
awọn ọmọ Ammoni, ati lọwọ awọn Filis-
tini, ati lọwọ Amaleki, ati ninu ikogun
Hadadeseri ọmọ Rehobu ọba Soba.
13 Dafidi si ni asiki gidigidi nigbati o
pada wá ile lati ibi pipa awọn ara Siria
li afonifoji iyọ̀, awọn ti o pa ję ęgbãsan
enia.
14 O si fi awọn ologun si Edomu; ati
ni gbogbo Edomu yika li on si fi ologun si,
gbogbo awọn ti o wà ni Edomu si wá sin
Dafidi. Oluwa si pa Dafidi mọ nibikibi ti
o nlọ.
15 Dafidi si jọba lori gbogbo Israeli;
Dafidi si şe idajọ ati otitọ fun awọn enia
rę̀.
16 Joabu ọmọ Seruia li o si nşe olori
ogun; Jehoşafati ọmọ Ahiludi si nşe
akọwe.
17 Ati Sadoku ọmọ Ahitubu, ati Ahime-
leki ọmọ Abiatari, li awọn alufa; Seruia a
si ma şe akọwe.
18 Benaiah ọmọ Jehoiada li o si nşe olori
awọn Kereti, ati awọn Peleti; awọn ọmọ
Dafidi si ję alaşę.

## ORI 9.

DAFIDI si bere pe, ọkan ninu awọn ęniti
işe idile Saulu kù sibę bi? ki emi ki
o le şe ore fun u nitori Jonatani.
2 Iranşę kan si ti wà ni idile Saulu,
orukọ rę̀ a ma ję Siba. Nwọn si pè e wá
sọdọ Dafidi, ọba si bere lọwọ rę̀ pe, Iwọ
ni Siba bi? O si dahùn wipe, Iranşę
rę ni.
3 Ọba si wipe, Kò ha si ọkan ninu idile
Saulu sibę, ki emi ki o şe ore Ọlọrun fun
u? Siba si wi fun ọba pe, Jonatani ní
ọmọ kan sibę ti o ya arọ.
4 Ọba si wi fun u pe, Nibo li o gbe wà?
Siba si wi fun ọba pe, Wŏ, on wà ni ile
Makiri, ọmọ Ammieli, ni Lodebari.
5 Dafidi ọba si ranşę, o si mu u lati ile
Makiri ọmọ Ammieli lati Lodebari wá.
6 Mefiboşeti ọmọ Jonatani ọmọ Saulu si
tọ̀ Dafidi wá, o si wolę niwaju rę̀, o si bu
ọla fun u. Dafidi si wipe, Mefiboşeti. On
si dahùn wipe, Wo iranşę rę!
7 Dafidi si wi fun u pe, Máşe bęru: ni-
toripe nitotọ emi o şe ore fun ọ nitori
Jonatani baba rę, emi o si tun fi gbogbo ilę
Saulu baba rę fun ọ: iwọ o si ma ba mi
jęun nigbagbogbo ni ibi onję mi.
8 On si tęriba, o si wipe, Kini iranşę rę
jasi, ti iwọ o fi ma wo okú aja bi emi?
9 Ọba si pe Siba iranşę Saulu, o si wi
fun u pe, Gbogbo nkan ti işe ti Saulu, ati
gbogbo eyi ti işe ti idile rę̀ li emi fi fun ọmọ
oluwa rę.
10 Iwọ, ati awọn ọmọ rę, ati awọn
iranşę rę ni yio si ma ro ilę na fun u, iwọ
ni yio si ma mu ikore wá, ọmọ oluwa rę
yio si ma ri onję ję: şugbọn Mefiboşeti
ọmọ oluwa rę yio si ma ba mi jęun ni-
gbagbogbo ni ibi onję mi. Siba si ni ọmọ
mẽdogun ati ogún iranşękọnrin.
11 Siba si wi fun ọba pe, Gęgę bi gbogbo
eyi ti oluwa mi ọba ti pa li aşę fun iranşę
rę, bęna ni iranşę rę o si şe. Ọba si wi pe,
Niti Mefiboşeti, yio ma jęun ni ibi onję mi,
gęgę bi ọkan ninu awọn ọmọ ọba.
12 Mefiboşeti si ni ọmọ kekere kan, oru-
kọ rę̀ nję Mika. Gbogbo awọn ti ngbe ni
ile Siba li o si nşe iranşę fun Mefiboşeti.
13 Mefiboşeti si ngbe ni Jerusalemu: on

Digitized by Google

a si ma jẹun nigbagbogbo ni ibi onjẹ ọba;
on si yarọ li ẹsẹ rẹ̀ mejeji.

## ORI 10.

O SI ṣe lẹhin eyi, ọba awọn ọmọ Ammoni
si kú, Hanuni ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
2 Dafidi si wipe, Emi o ṣe ore fun Ha-
nuni ọmọ Nahaṣi gẹgẹ bi baba rẹ̀ si ti ṣe
ore fun mi. Dafidi si ranṣẹ lati tù u ninu
lati ọwọ́ awọn iranṣẹ rẹ̀ wá, nitori ti baba
rẹ̀. Awọn iranṣẹ Dafidi si wá si ilẹ awọn
ọmọ Ammoni.
3 Awọn olori awọn ọmọ Ammoni si wi
fun Hanuni oluwa wọn pe, Li oju rẹ, ọlá
ni Dafidi mbù fun baba rẹ, ti o fi ran
awọn olutùnú si ọ? ko ha se pe, Dafidi ran
awọn iranṣẹ rẹ̀ si ọ, lati wa wò ilu, ati lati
ṣe alami rẹ̀, ati lati bà a jẹ?
4 Hanuni si mu awọn iranṣẹ Dafidi, o fá
apakan irungbọ̀n wọn, o si ke abọ̀ kuro ni
agbáda wọn, titi o fi de idi wọn, o si rán
wọn lọ.
5 Nwọn si sọ fun Dafidi, o si ranṣẹ lọ
ipade wọn, nitoriti oju ti awọn ọkọnrin na
pupọ̀: ọba si wipe, Ẹ duro ni Jeriko titi
irungbọ̀n nyin yio fi hù, nigbana ni ki ẹ
bọ̀.
6 Awọn ọmọ Ammoni si ri pe, nwọn di
ẹni irira niwaju Dafidi, awọn ọmọ Ammoni
si ranṣẹ, nwọn si fi owo bẹ̀ ogun awọn ara
Siria ti Betrehobu; ati Siria ti Soba, ẹgbã-
wa ẹlẹsẹ ati ti ọba Maaka, ẹgbẹrun ọkọnrin,
ati ti Iṣtobu ẹgbãfa ọkọnrin.
7 Dafidi si gbọ́, o si rán Joabu, ati gbo-
gbo ogun awọn ọkọnrin alagbara.
8 Awọn ọmọ Ammoni si jade, nwọn si
tẹ́ ogun li ẹnu odi; ara Siria ti Soba, ati ti
Rehobu, ati Iṣtobu, ati Maaka, nwọn si tẹ́
ogun ni papa fun ara wọn.
9 Nigbati Joabu si ri i pe ogun na doju
kọ on niwaju ati lẹhin, o si yàn ninu gbo-
gbo awọn akikanju ọkọnrin ni Israeli, o si
tẹ́ ogun kọju si awọn ara Siria.
10 O si fi awọn enia ti o kù le Abiṣai
aburo rẹ̀ lọwọ, ki o le tẹ́ ogun kọju si awọn
ọmọ Ammoni.
11 O si wipe, Bi agbara awọn ara Siria
ba si pọ̀ jù emi lọ, iwọ o si wá ràn mi
lọwọ: ṣugbọn bi ọwọ́ awọn ọmọ Ammoni
ba si pọ̀ jù ọ lọ, emi o si wá ràn ọ lọwọ.
12 Mu ọkàn le, jẹ ki a ṣe onigboya
nitori awọn enia wa, ati nitori awọn ilu
Ọlọrun wa; Oluwa o si ṣe eyi ti o dara li
oju rẹ̀.
13 Joabu ati awọn enia ti mbẹ lọdọ rẹ̀ si
ba awọn ara Siria pade ijà: nwọn si sa
niwaju rẹ̀.
14 Nigbati awọn ọmọ Ammoni si ri pe
awọn ara Siria sá, awọn si sá niwaju Abiṣai,
nwọn si wọ inu ilu lọ. Joabu si pada kuro
lẹhin awọn ọmọ Ammoni, o si bọ̀ wá si
Jerusalemu.
15 Nigbati awọn ara Siria si ri pe nwọn
di bibì ṣubu niwaju Israeli, nwọn si ko ara
wọn jọ.
16 Hadareseri si ranṣẹ, o si mu awọn ara
Siria ti o wà li oke odo jade wá: nwọn si
wá si Helami; Ṣobaki olori ogun ti Hada-
reseri si ṣolori wọn.
17 Nigbati a sọ fun Dafidi, o si ko gbo-
gbo Israeli jọ, nwọn si kọja Jordani, nwọn
si wá si Helami. Awọn ara Siria si tẹ́
ogun kọju si Dafidi, nwọn si ba a jà.
18 Awọn ara Siria si sa niwaju Israeli;
Dafidi si pa ninu awọn ara Siria ọdẹgbẹrin
awọn onikẹkẹ́, ati ọkẹ meji ẹlẹṣin, nwọn si
kọlu Ṣobaki olori ogun wọn, o si kú nibẹ.
19 Nigbati gbogbo awọn ọba ti o wà
labẹ Hadareseri si ri pe nwọn di bibì ṣubu
niwaju Israeli, nwọn si ba Israeli lajà,
nwọn si nsìn wọn. Awọn ara Siria si bẹ̀ru
lati ràn awọn ọmọ Ammoni lọwọ mọ.

## ORI 11.

O SI ṣe, lẹhin igbati ọdun yipo, li akoko
igbati awọn ọba ima jade ogun, Dafidi
si rán Joabu, ati awọn iranṣẹ rẹ̀ pẹlu rẹ̀, ati
gbogbo Israeli; nwọn si pa awọn ọmọ Am-
moni, nwọn si dó ti Rabba. Dafidi si joko
ni Jerusalemu.
2 O si ṣe, ni igbà aṣalẹ kan, Dafidi si
dide ni ibusùn rẹ̀, o si nrìn lori orule ile
ọba, lati ori orule na li o si ri obirin kan ti
o nwẹ̀ ara rẹ̀; obirin na si ṣe arẹwa jọjọ
lati wò.
3 Dafidi si ranṣẹ, o si bere obirin na.
Ẹnikan si wipe, Eyi kọ Batṣeba, ọmọbirin
Eliami, aya Uria ará Hitti?
4 Dafidi si rán awọn iranṣẹ, o si mu u;
on si wọ inu ilẹ tọ̀ ọ lọ, on si ba a dapọ̀;
nigbati o si wẹ ara rẹ̀ mọ́ tan, o si pada lọ
si ile rẹ̀.
5 Obirin na si fẹra kù, o si ranṣẹ o si sọ
fun Dafidi, o si wipe, Emi fẹra kù.
6 Dafidi si ranṣẹ si Joabu, pe, Ran Uria
ará Hitti si mi. Joabu si ran Uria si
Dafidi.
7 Nigbati Uria si de ọdọ rẹ̀, Dafidi si bi
i li ere alafia Joabu, ati alafia awọn enia na,
ati bi ogun na ti nṣe.

Digitized by Google

8 Dafidi si wi fun Uria pe, Sọkalẹ lọ si
ile rẹ, ki o si wẹ ẹsẹ rẹ. Uria si jade kuro
ni ile ọba, onjẹ lati ọdọ ọba wá si tọ ọ
lẹhin.
9 Ṣugbọn Uria sùn li ẹnu-ọ̀na ile ọba
lọdọ gbogbo iranṣẹ oluwa rẹ̀, kò si sọkalẹ lọ
si ile rẹ̀.
10 Nigbati nwọn si sọ fun Dafidi pe,
Uria kò sọkalẹ lọ si ile rẹ̀, Dafidi si wi fun
Uria pe, Ṣe ọ̀na àjo ni iwọ ti wá? eha ti ṣe
ti iwọ kò fi sọkalẹ lọ si ile rẹ?
11 Uria si wi fun Dafidi pe, Apoti-ẹri, ati
Israeli, ati Juda joko ninu agọ; ati Joabu
oluwa mi, ati awọn iranṣẹ oluwa mi wà ni
ibudo ni pápa: emi o ha lọ si ile mi, lati
jẹ ati lati mu, ati lati ba obirin mi sùn? bi
iwọ ba wà lãye, ati bi ẹmi rẹ si ti mbẹ lãye,
emi kì yio ṣe nkan yi.
12 Dafidi si wi fun Uria pe, Si duro ni-
hin loni, li ọla emi o si jẹ ki iwọ ki o lọ.
Uria si duro ni Jerusalemu li ọjọ na, ati ijọ
keji.
13 Dafidi si pè e, o si jẹ, o si mu niwaju
rẹ̀; o si mu ki ọti ki o pa a: on si jade li alẹ
lọ si ibusùn rẹ̀ lọdọ awọn iranṣẹ oluwa rẹ̀,
kò si sọkalẹ lọ si ile rẹ̀.
14 O si ṣe li owurọ Dafidi si kọwe si
Joabu, o fi rán Uria.
15 O si kọ sinu iwe pe, Fi Uria siwaju
ibi ti ogun gbe le, ki ẹ si bó o silẹ, ki nwọn
le kọ lù u, ki o si kú.
16 O si ṣe nigbati Joabu ṣe akiyesi ilu
na, o si yàn Uria si ibi kan ni ibi ti on mọ̀
pe awọn alagbara ọkọnrin mbẹ nibẹ.
17 Awọn ọkọnrin ilu na si jade wá, nwọn
si ba Joabu jà: diẹ si ṣubu ninu awọn enia
na ninu awọn iranṣẹ Dafidi; Uria ará Hitti
si kú pẹlu.
18 Joabu si ranṣẹ o si rò gbogbo nkan
ogun na fun Dafidi.
19 O si paṣẹ fun iranṣẹ na pe, Nigbati
iwọ ba si pari ati ma rò gbogbo nkan ogun
na fun ọba,
20 Bi o ba ṣe pe, ibinu ọba ba fàru, ti
on si wi fun ọ pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi sunmọ ilu
na lati ba wọn jà, ẹnyin kò mọ̀ pe nwọn o
tafà lati ori odi wá?
21 Tali o pa Abimeleki ọmọ Jerubbeṣeti?
Ki iṣe obirin li o yi okuta ọlọ lù u lati ori
odi wá, ti o si kú ni Tebeṣi? ẽha ti ri ti
ẹnyin fi sunmọ odi na? Iwọ o si wi fun u
pe, Uria iranṣẹ rẹ ará Hitti kú pẹlu.
22 Iranṣẹ na si lọ, o si wá, o si jẹ gbo-
gbo iṣẹ ti Joabu ran a fun Dafidi.
23 Iranṣẹ na si wi fun Dafidi pe, Nitõtọ
awọn ọkọnrin na lagbara jù wa lọ, nwọn si
jade tọ̀ wa wá ni pápa, awa si tẹle wọn titi
nwọn fi de ẹhin odi.
24 Awọn tafàtafa si ta si iranṣẹ rẹ lati
ori odi wá, diẹ ninu awọn iranṣẹ ọba si kú,
iranṣẹ rẹ Uria ará Hitti si kú pẹlu.
25 Dafidi si wi fun iranṣẹ na pe, Bayi ni
iwọ o wi fun Joabu pe, Máṣe jẹ ki nkan yi
ki o buru li oju rẹ, nitoripe idà a ma je li
ọtun li òsi, mu ijà rẹ le si ilu na, ki o si bì
i ṣubu: ki iwọ ki o si mu u lọkàn le.
26 Nigbati aya Uria si gbọ́ pe Uria ọkọ
rẹ̀ kú, o si gbawẹ̀ nitori ọkọ rẹ̀.
27 Nigbati awẹ̀ na si kọja tan, Dafidi si
ranṣẹ, o si mu u wá si ile rẹ̀, on si wa di
aya rẹ̀, o si bi ọmọkọnrin kan fun u. Ṣu-
gbọn nkan na ti Dafidi ṣe buru niwaju
Oluwa.

## ORI 12.

OLUWA si ran Natani si Dafidi. On si
tọ̀ ọ wá, o si wi fun u pe, Ọkọnrin
meji mbẹ ni ilu kan; ọkan jẹ ọlọrọ̀, ekeji
si jẹ talaka.
2 Ọkọnrin ọlọrọ̀ na si ni agutan ati
malu li ọ̀pọlọpọ,
3 Ṣugbọn ọkọnrin talaka na kò si ni
nkan, bikoṣe agutan kekere kan, eyi ti o ti
rà ti o si ntọ́: o si dagba li ọwọ́ rẹ̀ pẹlu
awọn ọmọ rẹ̀; a ma jẹ ninu onjẹ rẹ̀, a si
ma mu ninu ago rẹ̀, a si ma dubulẹ li aiya
rẹ̀, o si dabi ọmọbirin kan fun u.
4 Alejo kan si tọ̀ ọkọnrin ọlọrọ̀ na wá,
on kò si fẹ mu ninu agutàn rẹ̀, ati ninu
malu rẹ̀, lati fi ṣe alejo fun ẹni ti o tọ̀ ọ
wá: o si mu agutan ọkọnrin talaka na fi
ṣe alejo fun ọkọnrin ti o tọ̀ ọ wá.
5 Ibinu Dafidi si fàru gidigidi si ọkọn-
rin na; o si wi fun Natani pe, Bi Oluwa
ti mbẹ lãye, ọkọnrin na ti o ṣe nkan yi,
kikú ni yio kú.
6 On o si san agutan na pada ni mẹrin-
mẹrin, nitoriti o ṣe nkan yi, ati nitoriti kò
ni ãnu.
7 Natani si wi fun Dafidi pe, Iwọ li ọkọn-
rin na. Bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi,
Emi fi ọ jọba lori Israeli, emi si gbà ọ
lọwọ Saulu;
8 Emi si fi ile oluwa rẹ fun ọ, ati awọn
obirin oluwa rẹ si aiyà rẹ, emi si fi idile
Israeli ati ti Juda fun ọ; iba tilẹ ṣepe eyini
kere jù, emi iba si fun ọ ni nkan bayi
bayi.
9 Eṣe ti iwọ fi kẹgàn ọ̀rọ Oluwa, ti iwọ
fi ṣe nkan ti o buru li oju rẹ̀, ani ti iwọ fi
fi idà pa Uria ará Hitti, ati ti iwọ fi mu

Digitized by Google

obirin rẹ̀ lati fi ṣe obirin rẹ, o si fi idà
awọn ọmọ Ammoni pa a.
10 Njẹ nitorina idà ki yio kuro ni ilẹ rẹ
titi lai; nitoripe iwọ gàn mi, iwọ si mu
aya Uria ará Hitti lati fi ṣe aya rẹ.
11 Bayi li Oluwa wi, Kiye si i, Emi o jẹ
ki ibi ki o dide si ọ lati inu ile rẹ wá, emi
o si gbà awọn obirin rẹ loju rẹ, emi o si
fi wọn fun aladugbo rẹ, on o si ba awọn
obirin rẹ sùn niwaju õrun yi.
12 Ati pe iwọ ṣe e ni ikọ̀kọ: ṣugbon emi
o ṣe nkan yi niwaju gbogbo Israeli, ati
niwaju õrun.
13 Dafidi si wi fun Natani pe, Emi ṣẹ̀ si
Oluwa. Natani si wi fun Dafidi pe, Olu-
wa pẹlu si ti mu ẹ̀ṣẹ rẹ kuro; iwọ ki yio kú.
14 Ṣugbọn nitori nipa iwa yi, iwọ fi aye
silẹ fun awọn ọta Oluwa lati sọ ọ̀rọ ọ̀di,
ọmọ na ti a o bi fun ọ, kiku ni yio ku.
15 Natani si lọ si ile rẹ̀. Oluwa si fi
arùn kọlù ọmọ na ti obirin Uria bi fun
Dafidi, o si ṣe aisàn pupọ.
16 Dafidi si bẹ̀ Ọlọrun nitori ọmọ na,
Dafidi si gbàwẹ, o si wọ inu ile lọ, o si
dubulẹ lori ilẹ li oru na.
17 Awọn agbà ile rẹ̀ si dide tọ̀ ọ lọ, lati
gbe e dide lori ilẹ: o si kọ̀, kò si ba wọn
jẹun.
18 O si ṣe, ni ijọ keje, ọmọ na si kú.
Awọn iranṣẹ Dafidi si bẹ̀ru lati wi fun u pe,
ọmọ na kú; nitori ti nwọn wipe, Kiye si i,
nigbati ọmọ na mbẹ lãye, awa sọ̀rọ fun u,
on kò si gbọ́ ohùn wa: njẹ yio ti ṣé ara rẹ̀
ni iṣé to, bi awa ba wi fun u pe, ọmọ na kú?
19 Nigbati Dafidi si ri pe awọn iranṣẹ
rẹ̀ nsọ̀rọ kẹlẹkẹlẹ, Dafidi si kiye si i pe ọmọ
na kú: Dafidi si bere lọwọ awọn iranṣẹ rẹ̀
pe, Ọmọ na kú bi? nwon si da a li ohùn
pe, O kú.
20 Dafidi si dide ni ilẹ, o si wẹ̀, o fi oro-
ro pa ara, o si parọ̀ aṣọ rẹ̀, o si wọ inu ile
Oluwa lọ, o si wolẹ sin: o si wá si ile rẹ̀ o
si bere, nwọn si gbe onjẹ kalẹ niwaju rẹ̀, o
si jẹun.
21 Awọn iranṣẹ rẹ̀ si bi li ere pe, Ki li
eyi ti iwọ ṣe yi? nitori ọmọ na nigbati o
mbẹ lãye iwọ gbawẹ, o si sọkun; ṣugbọn
nigbati ọmọ na kú, o dide o si jẹun.
22 O si wipe, nigbati ọmọ na mbẹ lãye,
emi gbawẹ, emi si sọkun: nitoriti emi
wipe, Tali o mọ̀ bi Ọlọrun o ṣãnu mi, ki
ọmọ na ki o le yè.
23 Ṣugbọn nisisiyi o ti kú, nitori kili
emi o ṣe ma gbawẹ? emi le mu u pada wá
mọ bi? emi ni yio tọ̀ ọ lọ, on ki yio si tun
tọ̀ mi wá.
24 Dafidi si ṣipẹ fun Batṣeba aya rẹ̀, o si
wọle tọ̀ ọ, o si ba a dapọ̀: on si bi ọmọkọn-
rin kan, Dafidi si sọ orukọ rẹ̀ ni Solomo-
ni: Oluwa si fẹ ẹ.
25 O si rán Natani woli, o si pe orukọ
rẹ̀ ni Jedidiah nitori ti Oluwa.
26 Joabu si ba Rabba ti awọn ọmọ
Ammoni jagun, o si gbà ilu ọba wọn.
27 Joabu si ran awọn iranṣẹ si Dafidi, o
si wipe, emi ti ba Rabba jà, emi si ti gbà
ilu olomi wọnni.
28 Njẹ nitorina kó awọn ẹnia iyokù jọ,
ki o si dótì ilu na, ki o si gbà a, ki emi ki
o má ba gbà ilu na, ki a ma ba pè e li oru-
kọ mi.
29 Dafidi si kó gbogbo enia na jọ, o si
lọ si Rabba, o si ba a jà, o si gbà a.
30 On si gba adé ọba wọn kuro li ori rẹ̀,
wuwo rẹ̀ si jẹ talenti wura kan, o si ni oku-
ta oniyebiye lara rẹ̀: a si fi i dé Dafidi li
ori. On si kó ikogun ilu na li ọ̀pọlọpọ.
31 On si kó awọn enia na ti o wà ninu
rẹ̀, o si fi wọn si iṣẹ ayùn, ati si iṣẹ nkan
iwọlẹ ti a fi irin ṣe, ati si iṣẹ ãke irin, o si
fi wọn si iṣẹ ti tijõlò: bẹ̃na li on si ṣe si
gbogbo ilu awọn ọmọ Ammoni. Dafidi ati
gbogbo awọn enia na si pada si Jerusalemu.

## ORI 13.

O SI ṣe, lẹhin eyi, Absalomu ọmọ Dafidi
ni aburo obirin kan ti o ṣe arẹwà, oru-
kọ rẹ̀ a si ma jẹ́ Tamari; Amnoni ọmọ
Dafidi si fẹràn rẹ̀.
2 Amnoni si banujẹ titi o fi ṣe aisan
nitori Tamari aburo rẹ̀ obirin; nitoripe
wundia ni; o si ṣe ohun ti o ṣoro li oju
Amnoni lati ba a ṣe nkan kan.
3 Ṣugbọn Amnoni ni ọrẹ́ kan, orukọ rẹ̀
a si ma jẹ Jonadabu, ọmọ Ṣimea ẹgbọ́n
Dafidi: Jonadabu si jẹ alarekereke enia
gidigidi.
4 O si wi fun u pe, ẽṣe ti iwọ ọmọ ọba
nfi nrù lojojumọ bayi? o ki yio ha sọ fun
mi? Amnoni si wi fun u pe, emi fẹ Tamari
aburo Absalomu arakọnrin mi.
5 Jonadabu si wi fun u pe, dubulẹ ni
ibusùn rẹ ki iwọ ki o si dibọ́n pe iwọ kò
sàn: baba rẹ yio si wá iwò ọ, iwọ o si wi
fun u pe, Jọ̀wọ jẹ ki Tamari aburo mi ki o
wá ki o si fun mi li onjẹ ki o si se onjẹ na
niwaju mi ki emi ki o ri i, emi o si jẹ ẹ li
ọwọ́ rẹ̀.
6 Amnoni si dubulẹ, o si dibọ́n pe on
ṣaisan: ọba si wá iwò o, Amnoni si wi fun
ọba pe, Jọwọ, jẹ ki Tamari aburo mi ki o

Digitized by Google

wá, ki o si din akarà meji li oju mi, emi o
si jẹ li ọwọ́ rẹ̀.
7 Dafidi si ranṣẹ si Tamari ni ile pe, Lọ
si ile Amnoni ẹgbọ̀n rẹ, ki o si ṣe ti onjẹ
fun u.
8 Tamari si lọ si ile Amnoni ẹgbọ́n rẹ̀,
on si mbẹ ni ibulẹ. Tamari si mu iyẹfun,
o si pò o, o si fi ṣe akara li oju rẹ̀, o si din
akara na.
9 On si mu awo na, o si dà a sinu awo
miran niwaju rẹ̀; ṣugbọn o kọ̀ lati jẹ.
Amnoni si wipe, jẹ ki gbogbo ọkọnrin jade
kuro lọdọ mi. Nwọn si jade olukuluku
ọkọnrin kuro lọdọ rẹ̀.
10 Amnoni si wi fun Tamari pe, mu
onjẹ na wá si yara, emi o si jẹ lọwọ rẹ.
Tamari si mu akara ti o ṣe, o si mu u tọ̀
Amnoni ẹgbọ́n rẹ̀ ni iyẹwu.
11 Nigbati o si sunmọ ọ lati fi onjẹ fun
u, on si di i mu, o si wi fun u pe, wá,
dubulẹ tì mi, aburo mi.
12 On si da a lohùn wipe, Bẹ̃kọ, ẹgbọ́n
mi, máṣe té mi; nitoripe ko tọ́ ki a ṣe iru
nkan bẹ̃ ni Israeli, iwọ máṣe huwa were
yi.
13 Ati emi, nibo li emi o gbe itiju mi
wọ̀? iwọ o si dabi ọkan ninu awọn aṣiwere
ni Israeli. Njẹ nitorina, emi bẹ̀ ọ, sọ fun
ọba; nitoripe on kì yio kọ̀ lati fi mi fun ọ.
14 Ṣugbọn o kọ̀ lati gbọ́ ohùn rẹ̀; o si fi
agbara mu u, o si ṣẹgun rẹ̀, o si ba a dapọ̀.
15 Amnoni si korira rẹ̀ gidigidi, irira na
si wá jù ifẹ ti on ti ni si i ri lọ. Amnoni
si wi fun u pe, Dide, ki o si ma lọ.
16 On si wi fun u pe, Ko ha ni idi bi?
lilé ti iwọ nlé mi yi buru jù eyi ti iwọ ti ṣe
si mi lọ. Ṣugbọn on ko fẹ gbọ́ tirẹ̀.
17 On si pe ọmọ-ọdọ rẹ̀ ti iṣe iranṣẹ rẹ̀, o
si wi fun u pe, Jọwọ, tì obirin yi sode fun
mi, ki o si tì ilẹkùn mọ ọ.
18 On si ni aṣọ alaràbara kan li ara rẹ̀:
nitori iru aṣọ awọ̀leke bẹ̃ li awọn ọmọbirin
ọba ti iṣe wundia ima wọ̀. Iranṣẹ rẹ̀ si mu
u jade, o si ti ilẹkun mọ ọ.
19 Tamari si bu ẽru si ori rẹ̀, o si fa aṣọ
alaràbara ti mbẹ lara rẹ̀ ya, o si ka ọwọ́ rẹ̀
le ori, o si nkigbe bi o ti nlọ.
20 Absalomu ẹgbọ́n rẹ̀ si bi i lere pe,
Amnoni ẹgbọn rẹ ba ọ ṣe bi? njẹ aburo mi,
dakẹ; ẹgbọ́n rẹ ni iṣe; má fi nkan yi si
ọkàn rẹ. Tamari si joko ni ibanujẹ ni ile
Absalomu ẹgbọ́n rẹ̀.
21 Ṣugbọn nigbati Dafidi ọba gbọ́ gbo-
gbo nkan wọnyi, inu rẹ̀ bajẹ gidigidi.
22 Absalomu ko si ba Amnoni sọ nkan,
rere, tabi buburu: nitoripe Absalomu kori-
ra Amnoni nitori eyi ti o ṣe, ani ti o fi
agbara mu Tamari aburo rẹ̀.
23 O si ṣe, lẹhin ọdun meji, Absalomu
si ni olurẹrun agutan ni Baal-hasori, eyiti
o gbè Efraimu: Absalomu si pe gbogbo
awọn ọmọ ọba.
24 Absalomu si tọ̀ ọba wá, o si wipe,
Wõ, jọwọ, iranṣẹ rẹ ni olurẹrun agutan, emi
bẹ̀ ọ, jẹ ki ọba, ati awọn iranṣẹ rẹ̀ ba iranṣẹ
rẹ lọ.
25 Ọba si wi fun Absalomu pe, Bẹ̃kọ,
ọmọ mi, mo bẹ̀ ọ, má jẹ ki gbogbo wa lọ,
ki a má mu ọ nawọ pupọ. O si rọ ọ gidi-
gidi, ṣugbọn on kò fẹ lọ, o si sure fun u.
26 Absalomu si wi pe, Bi kò ba le ri bẹ̃,
emi bẹ̀ ọ, jẹ ki Amnoni ẹgbọ́n mi ba wa lọ.
Ọba si wipe, Idi rẹ̀ ti yio fi ba ọ lọ?
27 Absalomu si rọ̀ ọ, on si jẹ ki Amnoni
ati gbogbo awọn ọmọ ọba ba a lọ.
28 Absalomu si fi aṣẹ fun awọn iranṣẹ rẹ̀
pe, Ki ẹnyin ki o ma kiyesi akoko ti ọti-
waini yio mu ọkàn Amnoni dùn, emi o si
wi fun nyin pe, Kọlu Amnoni; ki ẹ si pa
a: ẹ má bẹ̀ru: ṣe emi li ọ fi aṣẹ fun nyin?
ẹ ṣe giri, ki ẹ ṣe bi alagbara ọmọ.
29 Awọn iranṣẹ Absalomu si ṣe si Amno-
ni gẹgẹ bi Absalomu ti paṣẹ. Gbogbọ awọn
ọmọ ọba si dide, olukuluku gun ibaka rẹ̀,
nwọn si sa.
30 O si ṣe, nigbati nwọn mbẹ li ọ̀na, ihìn
si de ọdọ Dafidi pe, Absalomu pa gbogbo
awọn ọmọ ọba, ọkan kò si kù ninu wọn.
31 Ọba si dide, o si fa aṣọ rẹ̀ ya, o si du-
bulẹ ni ilẹ; gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀ ti nwọn
duro tì i si fa aṣọ wọn ya.
32 Jonadabu ọmọ Ṣimea arakonrin Dafi-
di si dahùn o si wipe, Ki oluwa mi ọba ki
o máṣe rò pe nwọn ti pa gbogbo awọn ọdọ-
mọde-kọnrin awọn ọmọ ọba; nitoripe
Amnoni nikanṣoṣo li o kú: nitori lati ẹnu
Absalomu wá li a ti pinnu rẹ̀ lati ọjọ ti o ti
fi agbara mu Tamari aburo rẹ̀.
33 Njẹ ki oluwa mi ọba ki o máṣe fi
nkan yi si ọkàn pe, gbogbo awọn ọmọ ọba
li o kú: nitori Amnoni nikanṣoṣo li o kú.
34 Absalomu si sa. Ọdọmọkọnrin na ti
nṣọ́na si gbe oju rẹ̀ soke, o si ri pe, ọ̀pọ enia
mbọ̀ li ọ̀na lẹhin rẹ̀ lati iha oko wá.
35 Jonadabu si wi fun ọba pe, Wõ, awọn
ọmọ ọba mbọ̀: gẹgẹ bi ọ̀rọ iranṣẹ rẹ, bẹ̃ li
o ri.
36 O si ṣe, nigbati o ti pari ọ̀rọ isọ, si
wõ, awọn ọmọ ọba de, nwọn si gbe ohùn
wọn soke, nwọn si sọkun: ọba ati gbogbo
awọn iranṣẹ rẹ̀ pẹlu si sọkun nlanla.
37 Absalomu si sa. o si tọ̀ Talmai lọ,

Digitized by Google

ọmọ Ammihudu, ọba Geṣuri. Dafidi si
nkãnu nitori ọmọ rẹ̀, lojojumọ.
38 Absalomu si sa, o si lọ si Geṣuri, o si
gbe ibẹ li ọdun mẹta.
39 Ọkàn Dafidi ọba si fá gidigidi si
Absalomu: nitoriti o ti gbà ipẹ̀ niti Amno-
ni: o sa ti kú.

## ORI 14.

JOABU ọmọ Seruia si kiyesi i pe, ọkàn
ọba si fà si Absalomu.
2 Joabu si ranṣẹ si Tekoa, o si mu ọlọ-
gbọn obirin kan lati ibẹ̀ wá, o si wi fun u
pe, Emi bẹ̀ ọ, ṣe bi ẹniti nṣọfọ, ki o si fi
aṣọ ọfọ sara, ki o má si ṣe fi ororo pa ara,
ki o si dabi obirin ti o ti nṣọ̀fọ fun okú li
ọjọ pupọ̀.
3 Ki o si tọ̀ ọba wá, ki o si sọ fun u
gẹgẹ bi ọ̀rọ yi. Joabu si fi ọ̀rọ si i li ẹnu.
4 Nigbati obirin ará Tekoa na si nfẹ
sọ̀rọ fun ọba, o wolẹ, o dojubolẹ̀, o si bu
ọla fun u, o si wipe, Ọba, gbà mi.
5 Ọba si bi i lere pe, Ki li o ṣe ọ? on si
dahùn wipe, Nitõtọ, opó li emi iṣe, ọkọ mi
si kú.
6 Iranṣẹbirin rẹ si ti li ọmọkọnrin meji,
awọn mejeji si jọ jà li oko, kò si si ẹniti
yio là wọn, ekini si lu ekeji, o si pa a.
7 Si wõ, gbogbo idile dide si iranṣẹbirin
rẹ, nwọn si wipe, Fi ẹni ti o pa ẹnikeji rẹ̀
fun wa, awa o si pa a ni ipo ẹmi ẹnikeji rẹ̀
ti o pa, awa o si pa arole na run pẹlu:
nwọn o si pa iná mi ti o kù, nwọn kì yio
si fi orukọ tabi ẹni ti o kù silẹ fun ọkọ mi
li aiye.
8 Ọba si wi fun obirin na pe, Lọ si ile
rẹ, emi o si kilọ nitori rẹ.
9 Obirin ara Tekoa na si wi fun ọba pe,
Oluwa mi, ọba, jẹ ki ẹ̀ṣẹ na ki o wà lori mi,
ati lori idile baba mi; ki ọba ati itẹ rẹ̀ ki
o jẹ́ alailẹbi.
10 Ọba si wipe, Ẹnikẹni ti o ba sọ̀rọ si
ọ, mu oluwa rẹ̀ tọ̀ mi wá, on kì yio si tọ́ ọ
mọ.
11 O si wipe, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki ọba ki o
ranti Oluwa Ọlọrun rẹ̀, ki olugbẹsan ẹjẹ ki
o máṣe ni ipa lati ṣe iparun, ki nwọn ki o
má bà pa ọmọ mi; on si wipe, Bi Oluwa
ti mbẹ lãye, ọkan ninu irun ori ọmọ rẹ kì
yio bọ́ silẹ.
12 Obirin na si wipe, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki
iranṣẹbirin rẹ ki o sọ̀rọ kan fun oluwa mi
ọba; on si wipe, Ma wi.
13 Obirin na si wipe, Nitori kini iwọ si
ṣe ro iru nkan yi si awọn enia Ọlọrun?
nitoripe ọba si sọ nkan yi bi ẹniti o jẹbi,
nitipe ọba kò mu isánsa rẹ̀ bọ̀ wá ile.
14 Nitoripe awa o sa kú, a o si dabi omi
ti a tú silẹ ti a kò si le ṣajọ mọ; nitori bi
Ọlọrun kò ti gbà ẹmi rẹ̀, o si ti ṣe ọna ki
a má bà lé isánsa rẹ̀ kuro lọdọ rẹ̀,
15 Njẹ nitorina li emi si ṣe wá isọ nkan
yi fun oluwa mi ọba, bi o jẹpe awọn enia
ti dẹrubà mi; iranṣẹbirin rẹ si wi pe, Njẹ
emi o sọ fun ọba; o le ri bẽ pe ọba yio ṣe
ifẹ iranṣẹbirin rẹ̀ fun u.
16 Nitoripe ọba o gbọ́, lati gbà iranṣẹ-
birin rẹ̀ silẹ lọwọ ọkọnrin na ti o nfẹ ke
emi ati ọmọ mi pẹlu kuro ninu ilẹ ini
Ọlọrun.
17 Iranṣẹbirin rẹ si wipe, Njẹ ọ̀rọ ọba
oluwa mi yio si jasi itùnu: nitori bi angeli
Ọlọrun bẽ ni oluwa mi ọba lati mọ̀ rere ati
buburu: Oluwa Ọlọrun rẹ yio si wà pẹlu
rẹ.
18 Ọba si dahùn, o si wi fun obirin na
pe, Máṣe fi nkan ti emi o bere lọwọ rẹ
pamọ fun mi, emi bẹ̀ o. Obirin na si wipe,
Jẹ ki oluwa mi ọba ki o mã wi.
19 Ọba si wipe, Ọwọ́ Joabu kò ha wà
pẹlu rẹ ninu gbogbo eyi? obirin na si
dahun o si wipe, Bi ẹmi rẹ ti mbẹ lãye,
oluwa mi ọba, kò si iyipada si ọwọ́ ọtun,
tabi si ọwọ́ osi ninu gbogbo eyi ti oluwa
mi ọba ti wi: nitoripe Joabu iranṣẹ rẹ, on
li o rán mi, on li o si fi gbogbo ọ̀rọ wọnyi
si iranṣẹbirin rẹ li ẹnu.
20 Lati mu iru ọ̀rọ wọnyi wá ni Joabu
iranṣẹ rẹ si ṣe nkan yi: oluwa mi si gbọ́n,
gẹgẹ bi ọgbọ́n angeli Ọlọrun, lati mọ̀ gbo-
gbo nkan ti mbẹ li aiye.
21 Ọba si wi fun Joabu pe, Wõ, emi o
ṣe nkan yi: nitorina lọ, ki o si mu ọmọ-
dekọnrin na Absalomu pada wá.
22 Joabu si wolẹ o doju rẹ̀ bole, o si
tẹriba fun u, o si sure fun ọba: Joabu si
wipe, Loni ni iranṣẹ rẹ mọ̀ pe, emi ri ore-
ọfẹ gbà li oju rẹ, oluwa mi, ọba, nitoripe
ọba ṣe ifẹ iranṣẹ rẹ.
23 Joabu si dide, o si lọ si Geṣuri, o si
mu Absalomu wá si Jerusalemu.
24 Ọba si wipe, Jẹ ki o yipada lọ si ile
rẹ̀, má si ṣe jẹ ki o ri oju mi. Absalomu
si yipada si ile rẹ̀, kò si ri oju ọba.
25 Kò si si arẹwà kan ni gbogbo Israeli
ti a ba yìn bi Absalomu: lati atẹlẹsẹ rẹ̀ titi
de atari rẹ̀ kò si abùkun kan lara rẹ̀.
26 Nigbati o ba si rẹ́ irun ori rẹ̀ (nitoripe
li ọdọdun li on ima rẹ́ ẹ nitoriti a wuwo
fun u, on a si ma rẹ́ ẹ) on si wọ̀n irun ori
rẹ̀, o si jasi igba ṣekeli ninu òṣuwọn ọba.

Digitized by Google

27 A si bi ọmọkọnrin mẹta fun Absalomu ati ọmọbirin kan, orukọ rẹ̀ a si ma jẹ́ Tamari: on si jẹ obirin ti o li ẹwà loju.

28 Absalomu si joko li ọdun meji ni Jerusalemu kò si ri oju ọba.

29 Absalomu si ranṣẹ si Joabu, lati rán a si ọba; ṣugbọn on kò fẹ wá sọdọ rẹ̀; o si ranṣẹ lẹ̃keji on kò si fẹ wá.

30 O si wi fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe, Wõ, oko Joabu gbè ti emi, o si ni ọkà nibẹ; ẹ lọ ki ẹ si tinabọ̀ ọ. Awọn iranṣẹ Absalomu si tinabọ oko na.

31 Joabu si dide, o si tọ Absalomu wá ni ile, o si wi fun u pe, Ẽṣe ti awọn iranṣẹ rẹ fi tinabọ oko mi?

32 Absalomu si da Joabu lohùn pe, Wõ, emi ranṣẹ si ọ, wipe, Wá nihinyi, emi o si rán ọ lọ sọdọ ọba, lati wi pe, Kili emi ti Geṣuri wá si? iba sàn fun mi bi o ṣepe emi wà nibẹ̀ sibẹ. Njẹ emi nfẹ ri oju ọba; bi o ba si ṣe pe ẹ̀ṣẹ mbẹ li ara mi, ki o pa mi.

33 Joabu si tọ̀ ọba wá, o si rò fun u: o si ranṣẹ pe Absalomu, on si wá sọdọ ọba, o tẹriba fun u, o si doju rẹ̀ bolẹ niwaju ọba; ọba si fi ẹnu ko Absalomu li ẹnu.

## ORI 15.

O SI ṣe lẹhin eyi, Absalomu si pèse kẹkẹ́ ati ẹṣin fun ara rẹ̀, ati adọta ọmọkọnrin ti yio ma sare niwaju rẹ̀.

2 Absalomu si dide ni kutukutu, o si duro li apakan ọ̀na ẹnu ibode: o si ṣe, bi ẹnikan ba ni ẹjọ ti o nfẹ mu tọ̀ ọba wá fun idajọ, a si pè e sọdọ rẹ̀, a si bi i pe, Ara ilu wo ni iwọ? on a si dahùn pe, Iranṣẹ rẹ ti inu ọkan ninu ẹya Israeli wá.

3 Absalomu a si wi fun u pe Wõ, ọ̀ran rẹ sa dara, o si tọ: ṣugbọn ko si ẹnikan ti ọba fi aṣẹ fun lati yẹ ọ̀ran rẹ wò.

4 Absalomu a si wipe, A ba jẹ fi mi ṣe onidajọ ni ilẹ yi! ki olukuluku ẹniti o ni ẹjọ tabi ọ̀ran kan ba le ma tọ̀ mi wa, emi iba si ṣe idajọ otitọ fun u.

5 Bẹ̃ni bi ẹnikan ba si sunmọ ọ lati teriba fun u, on a si nawọ́ rẹ̀, a si dì i mu, a si fi ẹnu kò o li ẹnu.

6 Iru iwà bayi ni Absalomu a ma hù si gbogbo Israeli ti o tọ̀ ọba wá nitori idajọ: Absalomu si fa ọkàn awọn enia Israeli sọdọ rẹ̀.

7 O si ṣe lẹhin ogoji ọdun, Absalomu si wi fun ọba pe, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki emi ki o lọ, ki emi o si san ileri mi ti emi ti ṣe fun Oluwa, ni Hebroni.

8 Nitori ti iranṣẹ rẹ ti jẹ'jẹ kan nigbati emi mbẹ ni Geṣuri ni Siria, pe, Bi Oluwa ba mu mi pada wá si Jerusalemu, nitotọ, emi o si sin Oluwa.

9 Ọba si wi fun u pe, Ma lọ li alafia. O si dide, o si lọ si Hebroni.

10 Ṣugbọn Absalomu rán amí sarin gbogbo ẹyà Israeli pe, Nigbati ẹnyin ba gbọ́ iró ipè, ki ẹnyin si wipe, Absalomu jọba ni Hebroni.

11 Igba ọkọnrin si bá Absalomu ti Jerusalemu jade, ninu awọn ti a ti pè; nwọn si lọ ninu aimọ̀kan wọn, nwọn kò si mọ nkankan.

12 Absalomu si ranṣẹ pè Ahitofeli ara Giloni, igbimọ̀ Dafidi, lati ilu rẹ̀ wá, ani lati Gilo, nigbati o nrú ẹbọ. Idìmọlu na si le; awọn enia si npọ̀ sọdọ Absalomu.

13 Ẹnikan si wá rò fun Dafidi pe, Ọkàn awọn ọkọnrin Israeli ṣi si Absalomu.

14 Dafidi si wi fun gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀ ti o wà lọdọ rẹ̀ ni Jerùsalemu pe, Ẹ dide, ẹ jẹ ki a salọ, nitoripe kò si ẹniti yio gbà wa lọwọ Absalomu: ẹ yara, ki a lọ kuro, ki on má ba yara le wa ba, ki o má si mu ibi ba wa, ki o má si fi oju idà pa ilu run.

15 Awọn iranṣẹ ọba si wi fun ọba pe, Gẹgẹ bi gbogbo eyi ti oluwa wa ọba nfẹ, wõ, awa iranṣẹ rẹ ti mura.

16 Ọba si jade, gbogbo ile rẹ̀ si tẹle e. Ọba si fi mẹwa ninu awọn obirin rẹ̀ silẹ lati ma ṣọ ile.

17 Ọba si jade, gbogbo enia si tẹle e, nwọn si duro ni ibikan ti o jina.

18 Gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀ si kọja li ọtún li osì rẹ̀, ati gbogbo awọn Kereti, ati gbogbo awọn Peleti, ati gbogbo awọn Giti, ẹgbẹta ọmọkọnrin ti ntọ̀ ọ lẹhin lati Gati wá, si kọja niwaju ọba.

19 Ọba si wi fun Ittai, ara Giti nì pe, Ẽṣe ti iwọ fi mba wa lọ pẹlu? pada, ki o si ba ọba joko: nitoripe alejo ni iwọ, iwọ si ti fi ilu rẹ silẹ.

20 Lana yi ni iwọ de, emi ha si le mu ki iwọ ma ba wa lọ kakiri loni bi? emi nlọ si ibikibi ti mo ba ri: pada, ki o si mu awọn arakọnrin rẹ pada, ki ãnu ati otitọ ki o pẹlu rẹ.

21 Ittai si da ọba lohùn, o si wipe, Bi Oluwa ti mbẹ lãye, ati bi oluwa mi ọba ti mbẹ lãye, nitotọ nibikibi ti oluwa mi ọba ba gbe wà, ibakàn ṣe ninu ikú, tabi ninu ìye, nibẹ pẹlu ni iranṣẹ rẹ yio gbe wà.

22 Dafidi si wi fun Ittai pe, Lọ ki o si

Digitized by Google

rekọja. Ittai ará Giti nì si rekọja, ati gbo-
gbo awọn ọmọkọnrin rẹ̀, ati gbogbo awọn
ọmọ kekeke ti o wà lọdọ rẹ̀.
23 Gbogbo ilu na si fi ohùn rara sọkun,
gbogbo enia si rekọja; ọba si rekọja odo
Kidroni, gbogbo awọn enia na si rekọja, si
ihà ọ̀na iju.
24 Si wõ, Sadoku pẹlu ati gbogbo awọn
ọmọ Lefi ti o wà lọdọ rẹ̀ si nru apoti-ẹri
Ọlọrun: nwọn si gbe apoti-ẹri Ọlọrun na
kalẹ; Abiatari si goke, titi gbogbo awọn
enia si fi dẹkun ati ma kọja lati ilu wá.
25 Ọba si wi fun Sadoku pe, Si tun gbe
apoti-ẹri Ọlọrun na pada si ilu: bi emi ba
ri oju rere gbà lọdọ Oluwa, yio si tun mu
mi pada wá, yio si fi apoti-ẹri na hàn mi
ati ibugbe rẹ̀.
26 Ṣugbọn bi on ba si wi pe, Emi kò ni
inu didùn si ọ; wõ, emi nĩ, jẹ ki on ki o
ṣe si mi gẹgẹ bi o ti tọ́ li oju rẹ̀.
27 Ọba si wi fun Sadoku alufa pe, Iwọ
kọ́ ariran? pada si ilu li alafia, ati awọn
ọmọ rẹ mejeji pẹlu rẹ, Ahimaasi ọmọ rẹ,
ati Jonatani ọmọ Abiatari.
28 Wõ, emi o duro ni pẹtẹlẹ iju nì, titi
ọ̀rọ o fi ti ọdọ rẹ wá lati sọ fun mi.
29 Sadoku ati Abiatari si gbe apoti-ẹri
Ọlọrun pada si Jerusalemu: nwọn si gbe
ibẹ̀.
30 Dafidi si ngoke lọ ni oke Igi ororo, o
si nsọkun bi on ti ngoke lọ, o si bò ori rẹ̀,
o nlọ laini bata li ẹsẹ: gbogbo enia ti o wà
lọdọ rẹ̀, olukuluku ọkọnrin si bò ori rẹ̀,
nwọn si ngoke, nwọn si nsọkun bi nwọn ti
ngoke lọ.
31 Ẹnikan si sọ fun Dafidi pe, Ahitofeli
wà ninu awọn adìmọlu Absalomu. Dafidi
si wipe, Oluwa, emi bẹ̀ ọ, sọ ìmọ Ahitofeli
di asan.
32 O si ṣe, Dafidi de ori oke, nibiti o
gbe wolẹ sin Ọlọrun, si wõ, Huṣai ara Arki
nì si wá lati pade rẹ̀ ti on ti aṣọ rẹ̀ yiya,
ati erupẹ, li ori rẹ̀.
33 Dafidi si wi fun u pe, bi iwọ ba bá
mi kọja, iwọ o si jẹ idiwọ fun mi.
34 Bi iwọ ba si pada si ilu, ti o si wi fun
Absalomu pe, Emi o ṣe iranṣẹ rẹ, ọba, gẹgẹ
bi emi ti ṣe iranṣẹ baba rẹ nigba atijọ, bẽli
emi o si jẹ iranṣẹ rẹ nisisiyi: ki iwọ ki o si
bà ìmọ Ahitofeli jẹ.
35 Ṣe Sadoku ati Abiatari awọn alufa
wà nibẹ pẹlu rẹ? yio si ṣe, ohunkohun
ti iwọ ba gbọ́ lati ile ọba wá, iwọ o si sọ
fun Sadoku ati Abiatari awọn alufa.
36 Wõ, nwọn si ni ọmọ wọn mejeji nibẹ
pẹlu wọn, Ahimaasi ọmọ Sadoku, ati Jona-
tani ọmọ Abiatari; lati ọwọ́ wọn li ẹnyin
o si rán ohunkohun ti enyin ba gbọ́ si
mi.
37 Huṣai ọrẹ Dafidi si wá si ilu, Absa-
lomu si wá si Jerusalemu.

## ORI 16.

NIGBATI Dafidi si fi diẹ kọja ori oke na,
si wõ, Siba iranṣẹ Mefiboṣeti si mbọ̀
wá ipade rẹ̀, ti on ti kẹtẹkẹtẹ́ meji ti a ti dì
li asá, ati igba iṣu akara li ori wọn, ati ọgọ-
run ṣiri ajara gbigbẹ, ati ọgọrun eso ẹrùn,
ati igò ọti-waini kan.
2 Ọba si wi fun Siba pe, Kini wọnyi?
Siba si wipe, Kẹtẹkẹtẹ wọnyi ni fun awọn
ara ile ọba lati ma gùn; ati akara yi, ati eso
ẹrùn yi ni fun awọn ọdọmọdekọnrin lati
jẹ; ati ọti-waini yi ni fun awọn alãrẹ ni
ijù lati mu.
3 Ọba si wipe, Ọmọ ọluwa rẹ da? Siba
si wi fun ọba pe, Wõ, o joko ni Jerusa-
lemu; nitoriti o wipe, Loni ni idile Israeli
yio mu ijọba baba mi pada fun mi wá.
4 Ọba si wi fun Siba pe, Wõ, gbogbo
nkan ti iṣe ti Mefiboṣeti jẹ tirẹ. Siba si
wipe, Mo tũba, jẹ ki nri ore-ọfẹ loju rẹ,
oluwa mi, Ọba.
5 Dafidi ọba si de Bahurimu, si wõ,
ọkọnrin kan ti ibẹ̀ jade wá, lati idile Saulu
wá, orukọ rẹ̀ a ma jẹ Ṣimei, ọmọ Gera: o
si nyan ẽbu bi o ti mbọ̀.
6 O si sọ okuta si Dafidi, ati si gbogbo
iranṣẹ Dafidi ọba, ati si gbogbo awọn enia,
gbogbo awọn alagbara ọkọnrin si wà lọwọ
ọtún rẹ̀ ati lọwọ osì rẹ̀.
7 Bayi ni Ṣimei si wi nigbati o nyan ẽbu,
Jade, jade, iwọ ọkọnrin ẹjẹ, iwọ ọkọnrin
Beliali.
8 Oluwa mu gbogbo ẹjẹ idile Saulu pada
wá si ori rẹ, ni ipo ẹniti iwọ jọba; Oluwa
ti fi ijọba na le Absalomu ọmọ rẹ lọwọ: si
wõ, iwa buburu rẹ li o mu eyi wá ba ọ,
nitoripe ọkọnrin ẹjẹ ni iwọ.
9 Abiṣai ọmọ Seruia si wi fun ọba pe,
Ẽṣe ti okú ajá yi fi mbu oluwa mi ọba? jẹ
ki emi kọja, emi bẹ̀ ọ, ki emi si bẹ́ ẹ li ori.
10 Ọba si wipe, Kili emi ni fi nyin ṣe,
ẹnyin ọmọ Seruia? jẹ ki o ma bu bẽ, ni-
toriti Oluwa ti wi fun u pe: Bu Dafidi.
Tani yio si wipe, Nitori kini iwọ fi ṣe bẽ?
11 Dafidi si wi fun Abiṣai, ati fun
gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀ pe, Wõ, ọmọ mi ti
o ti inu mi wá, nwá ẹmi mi kiri: njẹ
melomelo ni ara Benjamini yi yio si ṣe?
jọwọ rẹ̀, si jẹ ki o ma yan ẽbu; nitoripe
Oluwa li o sọ fun u.

Digitized by Google

12 Bọ̀ya Oluwa yio wo ipọnju mi, Oluwa
yio si fi ire san a fun mi ni ipo ẽbu rẹ̀ loni.
13 Dafidi ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀ si nlọ li
ọ̀na, Ṣimei si nrìn li ẹba oke ti o wà li
ẹgbẹ rẹ̀, o si nyan ẽbu bi o ti nlọ, o si nsọ
ọ li okuta, o si nfún erupẹ.
14 Ọba, ati gbogbo awọn enia ti o mbẹ
lọdọ rẹ̀ si wá ti awọn ti ãrẹ̀, nwọn si simi
nibẹ.
15 Absalomu ati gbogbo awọn enia, awọn
ọkọnrin Israeli si wá si Jerusalemu, Ahitofeli si wà pẹlu rẹ̀.
16 O si ṣe, nigbati Huṣai ará Arki, ọrẹ
Dafidi tọ Absalomu wá, Huṣai si wi fun
Absalomu pe, Ki ọba ki o pẹ, ki ọba ki
o pẹ.
17 Absalomu si wi fun Huṣai pe, Ore rẹ
si ọ̀rẹ rẹ ni eyi? ẽṣe ti iwọ kò ba ọrẹ rẹ lọ?
18 Huṣai si wi fun Absalomu pe, Bẽkọ
nitori ẹniti Oluwa, ati gbogbo awọn enia
yi, ati gbogbo awọn ọkọnrin Israeli ba yàn,
tirẹ̀ li emi o jẹ, on li emi o si ba joko.
19 Ẹwẹ̀, tani emi o si sìn? kò ha yẹ ki
emi ki o ma sìn niwaju ọmọ rẹ̀? gẹgẹ bi emi
ti nsìn ri niwaju baba rẹ, bẽli emi o ri niwaju rẹ.
20 Absalomu si wi fun Ahitofeli pe, Ẹ ba
ara nyin gbìmọ ohun ti awa o ṣe.
21 Ahitofeli si wi fun Absalomu pe,
Wọle tọ awọn obirin baba rẹ lọ, awọn ti
o fi silẹ lati ma ṣọ ile, gbogbo Israeli yio si
gbọ́ pe, iwọ di ẹni-irira si baba rẹ, ọwọ
gbogbo awọn ti o wà lọdọ rẹ yio si le.
22 Nwọn si tẹ agọ kan fun Absalomu li
orile; Absalomu si wọle tọ awọn obirin
baba rẹ̀ li oju gbogbo Israeli.
23 Ìmọ̀ Ahitofeli ti ima gbà nijọ wọnni,
o dabi ẹnipe enia mbere nkan li ọwọ́ Ọlọrun: bẽni gbogbo ìmọ Ahitofeli fun Dafidi
ati fun Absalomu si ri.

## ORI 17.

AHITOFELI si wi fun Absalomu pe, Emi
o si yan ẹgbãfa ọkọnrin emi o si dide,
emi o si lepa Dafidi li oru yi.
2 Emi o si yọ si i nigbati ãrẹ̀ ba mu
u ti ọwọ́ rẹ̀ si ṣe alaile, emi o si da a ni ijì:
gbogbo awọn enia ti o wà lọdọ rẹ̀ yio si sa,
emi o si kọlu ọba nikanṣoṣo:
3 Emi o si mu gbogbo awọn enia pada si
ọ; ọkọnrin na ti iwọ nwá si ri gẹgẹ bi
ẹnipe gbogbo wọn ti pada: gbogbo awọn
enia yio si wà li alafia.
4 Ọrọ na si tọ loju Absalomu, ati li oju
gbogbo awọn agbà Israeli.
5 Absalomu si wipe, Njẹ̀ pe Huṣai ará
Arki, awa o si gbọ́ eyi ti o wà li ẹnu rẹ̀
pẹlu.
6 Huṣai si de ọdọ Absalomu, Absalomu si wi fun u pe, Bayi ni Ahitofeli wi,
ki awa ki o ṣe bi ọ̀rọ rẹ̀ bi? bi kò ba si tọ
bẽ, iwọ wi.
7 Huṣai si wi fun Absalomu pe, Imọ̀ ti
Ahitofeli gbà nì, ko dara nisisiyi.
8 Huṣai si wipe, Iwọ mọ̀ baba rẹ ati
awọn ọmọkọnrin rẹ̀ pe alagabra ni nwọn,
nwọn si wà ni kikoro ọkàn bi amọ̀tẹkun
ti a gbà li ọmọ ni igbẹ: baba rẹ si jẹ jagunjagun ọkọnrin, kì yio ba awọn enia na
gbe pọ̀ li oru.
9 Kiyesi i o ti fi ara rẹ̀ pamọ nisisiyi ni
iho kan, tabi ni ibomiran: yio si ṣe, nigbati
diẹ ninu wọn ba kọ ṣubu, ẹnikẹni ti o ba
gbọ́ yio si wipe, Iparun si mbẹ ninu awọn
enia ti ntọ̀ Absalomu lẹhin.
10 Ẹniti o si ṣe alagbara, ti ọkàn rẹ̀ si
dabi ọkàn kiniun, yio si rẹ̀ ẹ: nitori gbogbo
Israeli ti mọ̀ pe alagbara ni baba rẹ, ati
pe, awọn ti mbẹ lọdọ rẹ̀ jẹ alagbara.
11 Nitorina emi damọ̀ran pe, Ki gbogbo
Israeli wọjọ pọ̀ sọ̀do rẹ, lati Dani titi de
Beerṣeba, gẹgẹ bi yanrin ti o wà leti okun
fun ọ̀pọlọpọ; ati pe, ki iwọ tikararẹ ki o
lọ si ogun na.
12 Awa o si yọ si i nibikibi ti awa o
gbe ri i, awa o si yi i ka bi irì iti sẹ̀ si ilẹ:
ani ọkan kì yio kù pẹlu rẹ̀ ninu gbogbo
awọn ọmọkọnrin ti o wà lọdọ rẹ̀.
13 Bi o ba si bọ si ilu kan, gbogbo
Israeli yio si mu okùn wá si ilu na, awa
o si fà a lọ si odo, titi a kì yio fi ri okuta
kekeke kan nibẹ.
14 Absalomu ati gbogbo ọkọnrin Israeli
si wipe, Ìmọ Huṣai ara Arki sàn jù ìmọ
Ahitofeli lọ. Nitori Oluwa fẹ lati yi ìmọ
rere ti Ahitofeli po, nitori ki Oluwa ki o le
mu ibi wá sori Absalomu.
15 Huṣai si wi fun Sadoku ati fun Abiatari awọn alufa pe, Bayi bayi ni Ahitofeli
ti ba Absalomu ati awọn agbà Israeli dámọran; bayi bayi li emi si làmọran.
16 Nitorina yara ranṣẹ nisisiyi ki o si sọ
fun Dafidi pe, Máṣe duro ni pẹtelẹ ijù nì
li alẹ yi, ṣugbọn yara rekọja, ki a má ba
gbe ọba mì, ati gbogbo awọn enia ti o
mbẹ lọdọ rẹ̀.
17 Jonatani ati Ahimaasi si duro ni Enrogeli; ọdọmọdebirin kan si lọ, o si sọ fun
wọn; awọn si lọ nwọn sọ fun Dafidi ọba
nitoripe ki a má ba ri wọn pe nwọn wọ ilu.
18 Ṣugbọn ọdọmọdekọnrin kan ri wọn, o
si wi fun Absalomu: ṣugbọn awọn mejeji

Digitized by Google

si yara lọ kuro, nwọn si wá si ile ọkọnrin
kan ni Bahurimu, ẹniti o ni kanga kan li
ọgbà rẹ̀, nwọn si sọkalẹ si ibẹ.
19 Obirin rẹ̀ si mu nkan o fi bo kanga
na, o si sa agbado sori rẹ̀; a kò si mọ̀.
20 Awọn iranṣẹ Absalomu si tọ obirin
na wá ni ile na, nwọn si bere pe, Nibo ni
Ahimaasi ati Jonatani gbe wà? obirin na si
wi fun wọn pe, Nwọn ti goke rekọja iṣan
odo ni. Nwọn si wá wọn kiri, nwọn kò si
ri wọn, nwọn si yipada si Jerusalemu.
21 O si ṣe, lẹhin igbati nwọn yẹra kuro
tan, awọn si jade kuro ninu kanga, nwọn
si lọ, nwọn si rò fun Dafidi ọba, nwọn si
wi fun Dafidi pe, Dide ki o si goke odo
kánkán: nitoripe bayi ni Ahitofeli gbìmọ
si ọ.
22 Dafidi si dide, ati gbogbo awọn enia
ti mbẹ lọdọ rẹ̀, nwọn si goke odo Jordani:
ki ilẹ to mọ́, ẹnikan kò kù ti kò goke odo
Jordani.
23 Nigbati Ahitofeli si ri pe nwọn kò
fi ìmọ tirẹ̀ ṣe, o si di kẹtẹkẹtẹ rẹ̀ ni gãri, o si
dide, o lọ ile rẹ̀, o si palẹ ile rẹ̀ mọ, o si so,
o si ku, a si sin i si iboji baba rẹ̀.
24 Dafidi si wá si Mahanaimu. Absa-
lomu si goke odò Jordani, on, ati gbogbo
awọn ọkọnrin Israeli pẹlu rẹ̀.
25 Absalomu si fi Amasa ṣe olori ogun
ni ipò Joabu: Amasa ẹniti iṣe ọmọ ẹnikan,
orukọ ẹniti a npè ni Itra, ara Israeli, ti o
wọle tọ Abigaili ọmọbirin Nahaṣi arabirin
Seruia, iyá Joabu.
26 Israeli ati Absalomu si do ni ilẹ
Gileadi.
27 O si ṣe, nigbati Dafidi si wá si Maha-
naimu, Ṣobi ọmọ Nahaṣi ti Rabba ti awọn
ọmọ Ammoni, ati Makiri ọmọ Ammieli ti
Lodebari, ati Barsillai ara Gileadi ti Roge-
limu,
28 Mu akete, ati ago, ati ohun-elo amọ̀,
ati alikama, ati ọkà, ati iyẹfun, ati agbado
didin, ati ẹ̀wa, ati erẽ, ati ẹ̀wa didin.
29 Ati oyin, ati ori-amọ, ati agutan, ati
wàrakasi malu, wá fun Dafidi, ati fun
awọn enia ti mbẹ lọdọ rẹ̀ lati jẹ: nitoriti
nwọn wi pe, ebi npa awọn enia, o si rẹ̀ wọn,
oungbẹ si ngbẹ wọn li aginju.

## ORI 18.

DAFIDI si kà awọn enia ti mbẹ lọdọ rẹ̀,
o si mu wọn jẹ balogun ẹgbẹgbẹrun,
ati balogun ọrọrun lori wọn.
2 Dafidi si fi idamẹta awọn enia na le
Joabu lọwọ, o si ran wọn lọ, ati idamẹta
le Abiṣai ọmọ Seruia aburo Joabu lọwọ, ati
idamẹta le Ittai ara Giti lọwọ. Ọba si wi
fun awọn enia na pe, nitotọ emi tikara mi
o si ba nyin lọ pẹlu.
3 Awọn enia na si wipe, Iwọ ki yio ba
wa lọ: nitoripe bi awa ba sa, nwọn kì yio
nani wa, tabi bi o tilẹ sẹpe idaji wa kú,
nwọn ki yio nani wa, nitoripe iwọ nikan
to ẹgbãrun wa: nitorina, o si dara ki iwọ
ki o ma ràn wa lọwọ lati ilu wá.
4 Ọba si wi fun wọn pe, Eyi ti o ba
tọ́ loju nyin li emi o ṣe. Ọba si duro li
apakan ẹnu odi, gbogbo awọn enia na si
jade ni ọ̀rọrún ati ni ẹgbẹgbẹrun.
5 Ọba si paṣẹ fun Joabu ati Abiṣai ati
Ittai pe, Ẹ tọju ọdọmọkọnrin na Absalomu
fun mi. Gbogbo awọn enia na si gbọ́ ni-
gbati ọba paṣẹ fun gbogbo awọn balogun
nitori Absalomu.
6 Awọn enia na si jade lati pade Israeli
ni pápá; ni igbó Efraimu ni nwọn gbe
pade ijà na.
7 Nibẹ li a gbe pa awọn enia Israeli
niwaju awọn iranṣẹ Dafidi, ọ̀pọlọpọ enia
li o ṣubu li ọjọ na, ani ẹgbãwa enia.
8 Ogun na si fọ́n ka kiri lori gbogbo ilẹ
na: igbógàn na si pa ọ̀pọ enia jù eyi ti
idà pa lọ li ọjọ na.
9 Absalomu si pade awọn iranṣẹ Dafidi.
Absalomu si gun ori ibaka kan, ibaka na
si gba abẹ ẹka nla igi pọ́nhan kan ti o
tobi lọ, ori rẹ̀ si kọ́ igi pọ́nhan na, on si
rọ̀ soke li agbedemeji ọrun on ilẹ; ibaka
na ti o wà labẹ rẹ̀ si lọ kurọ.
10 Ọkọnrin kan si ri i, o si wi fun
Joabu pe, Wõ, emi ri Absalomu rọ̀ lãrin
igi pọ́nhan kan.
11 Joabu si wi fun ọkọnrin na ti o sọ
fun u pe, Sa wõ, iwọ ri i, eha ti ṣe ti iwọ
kò fi lù u bolẹ nibẹ? emi iba si fun ọ ni
sekeli fadaka mẹwa, ati amure kan.
12 Ọkọnrin na si wi fun Joabu pe,
Biotilẹṣepe emi o gba ẹgbẹrun ṣekeli fadaka
si ọwọ́ mi, emi kì yio fi ọwọ́ mi kan ọmọ
ọba: nitoripe awa gbọ́ nigbati ọba kilọ
fun iwọ ati Abiṣai, ati Ittai, pe, Ẹ kiye
si i, ki ẹnikeni ki o má fi ọwọ́ kan ọdọmọ-
kọnrin na Absalomu.
13 Bi o ba ṣe bẽ emi iba ṣe ibi si ara mi:
nitoripe kò si ọràn kan ti o pamọ fun ọba,
iwọ tikararẹ iba si kọju ijà si mi pẹlu.
14 Joabu si wipe, emi kì yio duro bẽ
niwaju rẹ. O si mu ọ̀kọ mẹta lọwọ rẹ̀,
o si fi wọn gun Absalomu li ọkàn, nigbati
o si wà lãye li agbedemeji igi pọ̀nhan na.
15 Awọn ọdọmọdekọnrin mẹwa ti ima

Digitized by Google

ru ihamọra Joabu si yi Absalomu ka, nwọn
si kọlù u, nwọn si pa a.
16 Joabu si fún ipè, awọn enia na si
yipada ati mã lepa Israeli: nitori Joabu
ti pe awọn enia na pada.
17 Nwọn si gbe Absalomu, nwọn si
sọ ọ sinu iho nla kan ni igbogàn na,
nwọn si papó okuta pupọ jọ si i lori,
gbogbo Israeli si sa, olukuluku si inu
agọ rẹ̀.
18 Absalomu li ọjọ aiye rẹ̀ si mu, o si
mọ ọwọ̀n kan fun ara rẹ̀, ti mbẹ li afoni-
foji ọba: nitoriti o wipe, Emi kò ni ọmọ-
kọnrin ti yio pa orukọ mi mọ ni iranti:
on si pe ọwọ̀n na nipa orukọ rẹ̀: a si npè
e titi di oni, ni ọwọ Absalomu.
19 Ahimaasi ọmọ Sadoku si wipe, Jẹ ki
emi ki o sure nisisiyi, ki emi ki o si mu
ihìn tọ̀ ọba lọ, bi Oluwa ti gbẹsan rẹ̀ li ara
awọn ọta rẹ̀.
20 Joabu si wi fun u pe, Iwọ ki yio
mu ìhin lọ loni, ṣugbọn iwọ o mu ìhin
lọ ni ijọ miran: ṣugbọn loni yi iwọ kì
yio mu ìhin kan lọ, nitoriti ọmọ ọba ṣe
alaisi.
21 Joabu si wi fun Kuṣi pe, Lọ, ki iwọ
ki o rò ohun ti iwọ ri fun ọba. Kuṣi si
wolẹ fun Joabu, o si sare.
22 Ahimaasi ọmọ Sadoku si tun wi fun
Joabu pe, Jọwọ, bi o ti wu ki o ri, emi
o sare tọ Kuṣi lẹhin. Joabu si bi i pe,
Nitori kini iwọ o ṣe sare, ọmọ mi, iwọ
kò ri pe kò si ihìn rere kan ti iwọ o mu
lọ?
23 O si wi pe, Bi o ti wu ki o ri, emi
o sare. On si wi fun u pe, Sare. Ahi-
maasi si sare li ọ̀na pẹtẹlẹ, o si sare kọja
Kuṣi.
24 Dafidi si joko li ẹnu odi lãrin ilẹkun
meji: alore si goke orule bode lori odi,
o si gbe oju rẹ̀ soke, o si wò, wõ, ọkọnrin
kan nsare on nikan.
25 Alore na si kigbe, o si wi fun ọba;
ọba si wi pe, Bi o ba ṣe on nikan ni, ihìn
rere mbẹ li ẹnu rẹ̀. On si nsunmọ tosi.
26 Alore na si ri ọkọnrin miran ti nsare:
alore si kọ si ẹniti nṣọ bode, o si wi pe,
Wõ, ọkọnrin kan nsare on nikan, ọba si
wipe, Eyi na pẹlu nmu ihìn rere wá.
27 Alore na si wipe, Emi wo isare ẹniti
o wà niwaju, o dabi isare Ahimaasi ọmọ
Sadoku. Ọba si wi pe, Enia re ni, o si
nmu ihìn rere wá.
28 Ahimaasi si pè, o si wi fun ọba pe,
Alafia. On si wolẹ fun ọba, o dojubolẹ o
si wi pe, Alabukun fun li Oluwa Ọlọrun
rẹ, ẹniti o fi awọn ọkọnrin ti o gbe ọwọ́
wọn soke si oluwa mi ọba le ọ lọwọ.
29 Ọba si bere pe, Alafia fun Absalomu
ọmọdekọnrin nì bi? Ahimaasi si dahun
pe, Nigbati Joabu rán iranṣẹ ọba, ati emi
iranṣẹ rẹ, mo ri ọ̀pọ enia, ṣugbọn emi kò
mọ̀ idi rẹ̀.
30 Ọba si wi fun u pe, Yipada ki o si
duro nihin: On si yipada, o si duro jẹ.
31 Si wõ, Kuṣi de; Kuṣi si wi pe, Ihin
rere fun oluwa mi ọba: nitoriti Oluwa ti
gbẹsan rẹ loni lara gbogbo awọn ti o dide
si ọ.
32 Ọba si bi Kusi pe, Alafia kọ Absa-
lomu ọdọmọdekọnrin na wà bi? Kuṣi si
dahun pe, Ki awọn ọta oluwa mi ọba, ati
gbogbo awọn ti o dide si ọ ni ibi, ri bi
ọdọmọdekọnrin na.
33 Ọba si kẹdùn pupọ̀, o si goke lọ si
iyẹwu ti o wà lori oke bode, o si sọkun;
bayi li o si nwi bi o ti nlọ, ọmọ mi Absa-
lomu, ọmọ mi, ọmọ mi Absalomu! ã!
ibaṣepe emi li o kú ni ipò rẹ, Absalomu
ọmọ mi, ọmọ mi!

## ORI 19.

ASI rò fun Joabu pe, Wõ, ọba nsọkun,
o si ngbawẹ fun Absalomu.
2 Iṣẹgun ijọ na si di awẹ̀ fun gbogbo
awọn enia na, nitori awọn enia na gbọ́ ni
ijọ na bi inu oba ti bajẹ nitori ọmọ rẹ̀.
3 Awọn enia na si yọ́ lọ si ilu ni ijọ na
gẹgẹ bi awọn enia ti a dojuti a ma yọ́ lọ
nigbati nwọn nsá loju ijà.
4 Ọba si bo oju rẹ̀, ọba si kigbe li ohùn
rara pe, A! ọmọ mi Absalomu, Absalomu
ọmọ mi, ọmọ mi!
5 Joabu si wọ inu ile tọ ọba lọ, o si
wipe, Iwọ dojuti gbogbo awọn iranṣẹ rẹ
loni, awọn ti o gbà ẹmi rẹ là loni, ati ẹmi
awọn ọmọkọnrin rẹ, ati ti awọn ọmọbirin
rẹ, ati ẹmi awọn aya rẹ, ati ẹmi awọn
obirin rẹ.
6 Nitoripe iwọ fẹ awọn ọta rẹ, iwọ si
korira awọn ọrẹ rẹ. Nitoriti iwọ wi loni
pe, Iwọ kò nani awọn ọmọ ọba, tabi awọn
iranṣẹ: emi si ri loni pe, ibaṣepe Absalomu
wà lãye, ki gbogbo wa si kú loni, njẹ iba
dùnmọ ọ gidigidi.
7 Si dide nisisiyi, lọ, ki o si sọ̀rọ itùnú
fun awọn iranṣẹ rẹ: nitoripe emi fi Oluwa
bura, bi iwọ kò ba lọ, ẹnikan kì yio ba
ọ duro li alẹ yi: ati eyini yio si buru fun
ọ jù gbogbo ibi ti oju rẹ ti nri lati igbà
ewe rẹ wá titi o fi di isisiyi.
8 Ọba si dide, o si joko li ẹnu ọ̀na.

Digitized by Google

Nwọn si wi fun gbogbo awọn enia na pe,
Wõ, ọba joko li ẹnu ọ̀na. Gbogbo enia
si wá si iwaju ọba: nitoripe, Israeli ti sa,
olukuluku si àgọ rẹ̀.
9 Gbogbo awọn enia na si mba ara wọn
jà ninu gbogbo ẹya Israeli, pe, Ọba ti gbà
wa là lọwọ awọn ọta wa, o si ti gbà wa
kuro lọwọ awọn Filistini; on si wa sa
kuro ni ilu nitori Absalomu.
10 Absalomu, ti awa fi jọba lori wa si
kú li ogun: njẹ ẽṣe ti ẹnyin fi dakẹ ti
ẹnyin kò si sọ̀rọ kan lati mu ọba pada wá?
11 Dafidi ọba si ranṣẹ si Sadoku, ati
si Abiatari awọn alufa pe, Sọ fun awọn
agbà Juda, pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi kẹhin lati
mu ọba pada wá si ile rẹ̀? ọ̀rọ gbogbo
Israeli si ti de ọdọ ọba ani ni ile rẹ̀.
12 Ẹnyin li ará mi, ẹnyin li egungun
mi, ati ẹran ara mi: ẽsi ti ṣe ti ẹnyin fi
kẹhìn lati mu ọba pada wá?
13 Ki ẹnyin ki o si wi fun Amasa pe,
Egungun ati ẹran ara mi ki iwọ iṣe bi?
ki Ọlọrun ki o ṣe bẽ si mi ati ju bẽ lọ
pẹlu, bi iwọ kò ba ṣe olori ogun niwaju
mi titi, ni ipò Joabu.
14 On si yi ọkàn gbogbo awọn ọkọnrin
Juda, ani bi ọkàn enia kan; nwọn si ranṣẹ
si ọba, pe, Iwọ pada ati gbogbo awọn
iranṣẹ rẹ.
15 Ọba si pada, o si wá si odo Jordani.
Juda si wà si Gilgali, lati lọ ipade ọba,
ati lati mu ọba kọja odo Jordani.
16 Ṣimei ọmọ Gera, ara Benjamini ti
Bahurimu, o yara o si ba awọn ọkọnrin
Juda sọkalẹ lati pade Dafidi ọba.
17 Ẹgbẹrun ọmọkọnrin si wà lọdọ rẹ̀
ninu awọn ọmọkọnrin Benjamini, Siba
iranṣẹ ile Saulu, ati awọn ọmọkọnrin rẹ̀
mẽdogun ati ogún iranṣẹ si pẹlu rẹ̀; nwọn
si goke odo Jordani ṣaju ọba.
18 Ọkọ̀ ẹ̀ro kan ti rekọja lati kó awọn
enia ile ọba si oke, ati lati ṣe eyiti o tọ li
oju rẹ̀. Ṣimei ọmọ Gera wolẹ, o si doju-
bolẹ niwaju ọba, bi o ti goke odo Jordani.
19 O si wi fun ọba pe, Ki oluwa mi ki o
máṣe ka ẹ̀ṣẹ si mi li ọrùn, má si ṣe ranti
afojudi ti iranṣẹ rẹ ṣe li ọjọ ti oluwa mi ọba
jade ni Jerusalemu, ki ọba ki o má si fi
si inu.
20 Nitoripe iranṣẹ rẹ mọ̀ pe on ti ṣẹ̀; si
wõ, ni gbogbo idile Josefu emi li o kọ́ wá
loni lati sọkalẹ wá pade oluwa mi ọba.
21 Ṣugbọn Abiṣai ọmọ Seruia dahùn o si
wipe, Kò ha tọ́ ki a pa Ṣimei nitori eyi?
nitoripe on ti bú ẹni-àmi-ororo Oluwa.
22 Dafidi si wipe, Ki li o wà lãrin emi ati
ẹnyin, ẹnyin ọmọ Seruia, ti ẹ fi di ọta si
mi loni? a ha le pa enia kan loni ni Israeli?
o le ṣe pe emi kò mọ̀ pẹ, loni emi li ọba
Israeli?
23 Ọba si wi fun Ṣimei pe, Iwọ kì yio
kú. Ọba si bura fun u.
24 Mefiboṣeti ọmọ Saulu si sọkalẹ lati wá
pade ọba, kò wẹ ẹsẹ rẹ̀, kò si tọ́ irungbọ̀n
rẹ̀, bẽni kò si fọ aṣọ rẹ̀ lati ọjọ ti ọba ti jade
titi o fi di ọjọ ti o fi pada li alafia.
25 O si ṣe, nigbati on si wá si Jeru-
salemu lati pade ọba, ọba si wi fun u pe,
Ẽṣe ti iwọ kò fi ba mi lọ, Mefiboṣeti?
26 On si dahùn wipe, Oluwa mi, ọba,
iranṣẹ mi li o tàn mi jẹ; nitoriti iranṣẹ rẹ
ti wipe, Emi o di kẹtẹkẹtẹ ni gãri, emi o
gùn u, emi o si tọ̀ ọba lọ, nitoriti iranṣẹ rẹ
yarọ.
27 O si sọ̀rọ ibajẹ si iranṣẹ rẹ, fun oluwa
mi ọba, ṣugbọn bi angeli Ọlọrun li oluwa
mi ọba ri: nitorina ṣe eyi ti o dara loju rẹ.
28 Nitoripe gbogbo ile baba mi bi okú
enia ni nwọn sa ri niwaju oluwa mi ọba:
iwọ si fi ipò fun iranṣẹ rẹ larin awọn ti o
njẹun ni ibi onjẹ rẹ. Nitorina are kili emi
ni ti emi o fi ma ke pe ọba sibẹ.
29 Ọba si wi fun u pe, Ẽṣe ti iwọ fi nsọ
ọràn rẹ siwaju mọ? emi sa ti wipe, Ki iwọ
ati Siba pin ilẹ na.
30 Mefiboṣeti si wi fun ọba pe, Si jẹ ki o
mu gbogbo rẹ̀, bi oluwa mi ọba ba ti pada
bọ̀ wá ile rẹ̀ li alafia.
31 Barsillai ara Gileadi si sọkalẹ lati
Rogelimu wá, o si ba ọba goke odo Jordani,
lati ṣe ikẹ́ rẹ̀ si ikọja odo Jordani.
32 Barsillai si jẹ arugbo ọkọnrin gidi-
gidi, ẹni ogbó ọgọrin ọdun si ni: o si pese
ohun jijẹ fun ọba nigbati o ti wà ni Ma-
hanaimu; nitoripe ọkọnrin ọlọla li on iṣe.
33 Ọba si wi fun Barsillai pe, Iwọ wá
ba mi goke odo, emi o si ma bọ́ ọ ni Jeru-
salemu.
34 Barsillai si wi fun ọba pe, Ọjọ melo
ni ọdun ẹmi mi kù, ti emi o fi ba ọba goke
lọ si Jerusalemu?
35 Ẹni ogbó ọgọrin ọdun sa li emi loni:
emi le mọ̀ iyatọ ninu rere ati buburu?
iranṣẹ rẹ le mọ̀ adùn ohun ti emi njẹ tabi
ohun ti emi nmu bi? emi tun le mọ̀ adùn
ohùn awọn ọkọnrin ti nkọrin, ati awọn
obirin ti nkọrin bi? njẹ nitori kili iranṣẹ
rẹ yio ṣe jẹ́ iyọnu sibẹ fun oluwa mi ọba?
36 Iranṣẹ rẹ yio si sin ọba lọ diẹ goke
odo Jordani; ẽsi ṣe ti ọba yio fi san ẹsan
yi fun mi?
37 Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki iranṣẹ rẹ pada, emi o

Digitized by Google

si kú ni ilu mi, a o si sin mi ni iboji baba ati iya mi. Si wo Kimhamu iranṣẹ rẹ, yio ba oluwa mi ọba goke; iwọ o si ṣe ohun ti o ba tọ li oju rẹ fun u.
38 Ọba si dahùn wipe, Kimhamu yio ba mi goke, emi o si ṣe eyi ti o tọ loju rẹ fun u; ohunkohun ti iwọ ba si bere lọwọ mi, emi o ṣe fun ọ.
39 Gbogbo awọn enia si goke odo Jordani. Ọba si goke; ọba si fi ẹnu kò Barsillai li ẹnu, o si sure fun u; on si pada si ile rẹ̀.
40 Ọba si nlọ si Gilgali, Kimhamu si mba a lọ, gbogbo awọn enia Juda si nṣe ikẹ ọba, ati ãbọ awọn enia Israeli.
41 Si wõ, gbogbo awọn ọkọnrin Israeli si tọ ọba wá, nwọn si wi fun ọba pe, Ẽṣe ti awọn arakọnrin wa awọn ọkọnrin Juda fi ji ọ kuro, ti nwọn si fi mu oba ati awọn ara ile rẹ̀ goke odo Jordani, ati gbogbo awọn enia Dafidi pẹlu rẹ̀.
42 Gbogbo ọkọnrin Juda si da awọn ọkọnrin Israeli li ohùn pe, Nitoripe ọba bá wa tan ni; ẽṣe ti ẹnyin fi binu nitori ọran yi? awa jẹ ninu onjẹ ọba rara bi? tabi o fi ẹbun kan fun wa bi?
43 Awọn ọkọnrin Israeli si da awọn ọkọnrin Juda li ohùn pe, Awa ni ipa mẹwa ninu ọba, awa si ni ninu Dafidi jù nyin lọ, ẽsi ṣe ti ẹnyin kò fi kà wa si, ti imọ wa kò fi ṣaju lati mu ọba wa pada? ọ̀rọ awọn ọkọnrin Juda si le jù ọ̀rọ awọn ọkọnrin Israeli lọ.

## ORI 20.

ỌKỌNRIN Beliali kan si mbẹ nibẹ orukọ rẹ̀ si njẹ Ṣeba ọmọ Bikri ara Benjamini; o si fún ipè o si wipe, Awa kò ni ipa ni Dafidi, bẹ̃li awa kò ni ini ni ọmọ Jesse: ki olukuluku ọkọnrin lọ si agọ rẹ̀, ẹnyin Israeli.
2 Gbogbo awọn ọkọnrin Israeli si lọ kuro lẹhin Dafidi, nwọn si ntọ Ṣeba ọmọ Bikri lẹhin: ṣugbọn awọn ọkọnrin Juda si fi ara mọ́ ọba wọn lati odo Jordani wá titi o fi de Jerusalemu.
3 Dafidi si wá si ile rẹ̀ ni Jerusalemu; ọba si mu awọn obirin mẹwa ti iṣe alè rẹ̀, awọn ti o ti fi silẹ lati ma ṣọ́ ile. O si há wọn mọ ile, o si mbọ́ wọn, ṣugbọn kò si tun wọle tọ̀ wọn mọ, a si se wọn mọ titi di ọjọ ikú wọn, nwọn si wà bi opo.
4 Ọba si wi fun Amasa pe, Pe awọn ọkọnrin Juda fun mi niwọn ijọ mẹta oni, ki iwọ na ki o si wá nihinyi.
5 Amasa si lọ lati pe awọn ọkọnrin Juda: ṣugbọn o si duro pẹ jù akoko ti o fi fun u.
6 Dafidi si wi fun Abiṣai pe, Nisisiyi Ṣeba ọmọ Bikri yio ṣe wa ni ibi jù ti Absalomu lọ; iwọ mu awọn iranṣẹ oluwa rẹ, ki o si lepa rẹ̀, ki o ma ba ri ilu olodi wọ̀, ki o si bọ́ lọwọ wa,
7 Awọn ọmọkọnrin Joabu si jade tọ̀ ọ lọ, ati awọn Kereti, ati awọn Peleti, ati gbogbo awọn ọkọnrin alagbara: nwọn si ti Jerusalemu jade lọ, lati lepa Ṣeba ọmọ Bikri.
8 Nigbati nwọn de ibi okuta nla ti o wà ni Gibeoni, Amasa si ṣaju wọn. Joabu si di amùre si agbada rẹ̀ ti o wọ̀, o si sán idà rẹ̀ mọ idi, ninu akọ̀ rẹ̀, bi o si ti nlọ, o yọ jade.
9 Joabu si bi Amasa lere pe, Ara rẹ ko le bi, iwọ arakọnrin mi? Joabu si na ọwọ́ ọtún rẹ̀ di Amasa ni irungbọ̀n mu lati fi ẹnu kò o li ẹnu.
10 Ṣugbọn Amasa ko si kiyesi idà ti mbẹ li ọwọ́ Joabu: bẹ̃li on si fi gun u li ẽgun ìha ikarun, ifun rẹ̀ si tú dá silẹ, on kò si tun gún u mọ́; o si kú. Joabu ati Abiṣai arakọnrin rẹ̀ si lepa Ṣeba ọmọ Bikri.
11 Ọkan ninu awọn ọdọmọdekọnrin ti o wà lọdọ Joabu si duro tì i, o si wipe, Tali ẹni ti o ba fẹran Joabu? tali o si nṣe ti Dafidi, ki o ma tọ̀ Joabu lẹhin.
12 Amasa si nyira ninu ẹ̀jẹ larin ọ̀na. Ọkọnrin na si ri pe gbogbo enia si duro tì i, o si gbe Amasa kuro loju ọ̀na lọ sinu igbẹ́, o si fi aṣọ bò o, nigbati o ti ri pe ẹnikẹni ti o ba de ọdọ rẹ̀, a duro.
13 Nigbati o si gbe e kuro li oju ọ̀na, gbogbo enia si tọ̀ Joabu lẹhin lati lepa Ṣeba ọmọ Bikri.
14 On kọja ninu gbogbo ẹya Israeli si Abeli ati si Betmaaka, ati gbogbo awọn ara Beriti; nwọn si kó ara wọn jọ, nwọn si tọ̀ ọ lẹhin pẹlu.
15 Nwọn wá, nwọn si doti i ni Abeli ti Betmaaka, nwọn si mọdi tì ilu na, odi na si duro ti odi ilu na: gbogbo enia ti mbẹ lọdọ Joabu si ngbiyanju lati wó ogiri na lulẹ.
16 Obirin ọlọgbọ́n kan si kigbe soke lati ilu na wá, pe, Fetisilẹ, fetisilẹ, emi bẹ̀ nyin, sọ fun Joabu pe, Sunmọ ihinyi emi o si ba ọ sọ̀rọ.
17 Nigbati on si sunmọ ọdọ rẹ̀, obirin na si wipe, Iwọ ni Joabu bi? on si dahùn wipe, Emi na ni. Obirin na si wi fun u pe, Gbọ́ ọ̀rọ iranṣẹbirin rẹ. On si dahun wipe, Emi ngbọ́.
18 O si sọ̀rọ, wipe, Nwọn ti nwi ṣaju pe niti bibere, nwọn o bere ni Abeli: bẹ̃ni nwọn si pari ọ̀ran na.

Digitized by Google

19 Emi li ọkan ninu awọn ẹni alafia ati
olõtọ ni Israeli: iwọ nwá ọ̀na lati pa ilu
kan run ti o jẹ iyá ni Israeli: ẽṣe ti iwọ o
fi gbe ini Oluwa mì?
20 Joabu si dahùn wipe, Ki a má ri i,
ki a má ri i lọdọ mi pe emi gbé mì tabi
emi sì parun.
21 Ọràn na kò ri bẽ; ṣugbọn ọkọnrin
kan lati oke Efraimu, ti orukọ rẹ̀ njẹ Ṣeba,
ọmọ Bikri, li o gbe ọwọ́ rẹ̀ soke si ọba, ani
si Dafidi: fi on nikanṣoṣo le wa lọwọ, emi
o si fi ilu silẹ. Obirin na si wi fun Joabu
pe, Wõ, ori rẹ̀ li a o si sọ si ọ lati inu odi
wá.
22 Obirin na si mu ìmọran rẹ̀ tọ gbogbo
awọn enia na. Nwọn si bẹ́ Ṣeba ọmọ Bikri
li ori, nwọn si sọ ọ si Joabu. On si fún
ipè, nwọn si tuka kuro ni ilu na, olukuluku
si agọ rẹ̀. Joabu si pada lọ si Jerusalemu
ati sọdọ ọba.
23 Joabu si li olori gbogbo ogun Israeli:
Benaiah ọmọ Jehoiada si jẹ olori awọn
Kereti, ati olori awọn Peleti:
24 Adoramu si jẹ olori awọn agbowodè:
Jehoṣafati ọmọ Ahiludi si jẹ akọwe nkan ti
o ṣe ni ilu:
25 Ṣefa si jẹ akọwe: Sadoku ati Abiatari
si li awọn alufa.
26 Ira pẹlu, ara Jairi ni nṣe alufa lọdọ
Dafidi.

## ORI 21.

IYAN kan si mu li ọjọ Dafidi li ọdun
mẹta, lati ọdun de ọdun; Dafidi si bere
lọdọ Oluwa, Oluwa si wipe, Nitori ti Saulu
ni, ati nitori ile rẹ̀ ti o kún fun ẹ̀jẹ, nito-
ripe o pa awọn ara Gibeoni.
2 Ọba si pe awọn ara Gibeoni, o si ba
wọn sọ̀rọ: awọn ara Gibeoni ki iṣe ọkan
ninu awọn ọmọ Israeli, ṣugbọn nwọn jẹ
awọn ti o kù ninu awọn ọmọ Amori; awọn
ọmọ Israeli si ti bura fun wọn: Saulu si
nwá ọ̀na ati pa wọn ni itara rẹ̀ fun awọn
ọmọ Israeli ati Juda.
3 Dafidi si bi awọn ara Gibeoni lere pe,
Kili emi o ṣe fun nyin? ati kili emi o fi
ṣe etutu, ki ẹnyin ki o le sure fun ilẹ ini
Oluwa?
4 Awọn ara Gibeoni si wi fun u pe, Awa
kò ni fi fadaka tabi wura ti Saulu ati ti
idile rẹ̀ ṣe, bẽni a kò si fẹ ki ẹ pa ẹnikan ni
Israeli. O si wipe, eyi ti ẹnyin ba wi li
emi o ṣe.
5 Nwọn si wi fun ọba pe, Ọkọnrin ti o
run wa, ti o si rò lati pa wa rẹ́ ki a má kù
nibikibi ninu gbogbo agbegbe Israeli.
6 Mu ọkọnrin meje ninu awọn ọmọ rẹ̀
fun wa, awa o si so wọn rọ̀ fun Oluwa ni
Gibea ti Saulu ẹniti Oluwa ti yàn. Ọba si
wipe, Emi o fi wọn fun nyin.
7 Ṣugbọn Ọba dá Mefiboṣeti si, ọmọ
Jonatani, ọmọ Saulu, nitori ibura Oluwa
ti o wà larin wọn, lãrin Dafidi ati Jonatani
ọmọ Saulu.
8 Ọba si mu awọn ọmọkọnrin mejeji
ti Rispa ọmọbirin Aia bi fun Saulu, ani
Armoni ati Mefiboṣeti: ati awọn ọmọkọn-
rin mararun ti Merabu, ọmọbirin Saulu,
awọn ti o bi fun Adrieli ọmọ Barsillai ara
Meholati.
9 On si fi wọn le awọn ara Gibea lọwọ,
nwọn si so wọn rọ̀ lori oke niwaju Oluwa:
awọn mejeje si ṣubu lẹ̃kan, a si pa wọn ni
igbà ikore, ni ibẹrẹ ikore ọka-barle.
10 Rispa ọmọbirin Aia si mu aṣọ ọfọ̀
kan, o si tẹ́ ẹ fun ara rẹ̀ lori àpata, ni
ibẹrẹ ikore, titi omi fi dà si wọn lara lati
ọrun wá, kò si jẹ ki awọn ẹiyẹ oju ọrun bà
le wọn li ọsan, tabi awọn ẹranko igbẹ li oru.
11 A si rò eyi, ti Rispa ọmọbirin Aia
obirin Saulu ṣe, fun Dafidi.
12 Dafidi si lọ o si ko egungun Saulu,
ati egungun Jonatani ọmọ rẹ̀ kuro lọdọ
awọn ọkọnrin Jabeṣi-gileadi, awọn ti o ti ji
wọn kuro ni ita Betṣani, nibiti awọn Filis-
tini gbe so wọn rọ̀, nigbati awọn Filistini
pa Saulu ni Gilboa.
13 On si mu egungun Saulu ati egungun
Jonatani ọmọ rẹ̀ lati ibẹ na wá; nwọn si ko
egungun awọn ti a ti so rọ̀ jọ.
14 Nwọn si sin egungun Saulu ati ti
Jonatani ọmọ rẹ̀ ni ilẹ Benjamini, ni Sela,
ninu iboji Kiṣi baba rẹ̀: nwọn si ṣe gbogbo
eyi ti ọba pa li aṣẹ: lẹhin eyini Ọlọrun si
gbà ẹbẹ nitori ilẹ na.
15 Ogun si tun wà larin awọn Filistini
ati Israeli; Dafidi si sọkalẹ, ati awọn iranṣẹ
rẹ̀ pẹlu rẹ̀, o si ba awọn Filistini jà: o si
rẹ̀ Dafidi.
16 Iṣbi-benobu si jẹ ọkan ninu awọn
òmirán, ẹniti òṣuwọn ọ̀kọ rẹ̀ jẹ ọdunrun
ṣekeli idẹ, on si sán idà titun, o si gbero
lati pa Dafidi.
17 Ṣugbọn Abiṣai ọmọ Seruia si ràn a
lọwọ, o si kọlu Filistini na, o si pa a.
Nigbana ni awọn iranṣẹ Dafidi si bura fun
u, pe, Iwọ kì yio si tun ba wa jade lọ si ibi
ija mọ, ki iwọ ki o máṣe pa iná Israeli.
18 O si ṣe, lẹhin eyi, ija kan si tun wà
lãrin awọn Israeli ati awọn Filistini ni
Gobu: nigbana ni Sibbekai ara Huṣa pa
Safu, ẹniti iṣe ọkan ninu awọn òmirán.

Digitized by Google

19 Ija kan si tun wà ni Gobu lãrin awọn
Israeli ati awọn Filistini, Elhanani ọmọ
Jairi ara Betlehemu si pa arakọnrin Goliati
ara Gati, ẹniti ọpá ọ̀kọ rẹ̀ dabi idubú igi ti
a fi wun aṣọ.
20 Ija kan si tun wà ni Gati, ọkọnrin
kan si wà ti o gùn pupọ, o si ni ika mẹfa
li ọwọ́ kan, ati ọmọ-ẹsẹ mẹfa li ẹsẹ kan,
apapọ̀ rẹ̀ si jẹ mẹrinlelogun ; a si bi on'na
li ọ̀mirán.
21 Nigbati on si pe Israeli ni ijà, Jona-
tani ọmọ Ṣimei arakọnrin Dafidi si pa a.
22 Awọn mẹrẹrin wọnyi li a bi li ọ̀mirán
ni Gati, nwọn si ti ọwọ́ Dafidi ṣubu, ati
ọwọ́ awọn iranṣẹ rẹ̀.

## ORI 22.

DAFIDI si sọ ọ̀rọ orin yi si Oluwa li ọjọ
ti Oluwa gbà a kuro li ọwọ́ gbogbo
awọn ọta rẹ̀, ati kuro li ọwọ́ Saulu.
2 O si wipe, Oluwa li apata mi; ati odi
mi, ati olugbala mi;
3 Ọlọrun apata mi; emi o gbẹkẹle e:
asà mi, ati iwo igbala mi, ibi isadi giga mi,
ati ibi ilumọ́ mi, olugbala mi; iwọ li o ti
gbà mi kuro lọwọ agbara.
4 Emi o kepe Oluwa, ti o yẹ lati ma yìn:
a o si gbà mi lọwọ awọn ọta mi.
5 Nigbati ibilu irora ikú yi mi ka kiri,
ti awọn iṣàn enia buburu dẹruba mi;
6 Ọjá ipo-okú yi mi ka kiri; ikẹkun ikú
ti ṣaju mi.
7 Ninu ipọnju mi emi ke pe Oluwa, emi
si gbe ohùn mi soke si Ọlọrun mi: o si
gbohùn mi lati tempili rẹ̀ wá, igbe mi si
wọ́ eti rẹ̀.
8 Ilẹ si mì, o si wa-riri; ipilẹ ọrun wa-
riri, o si mì, nitoriti o binu.
9 Ẽfin si jade lati iho-imu rẹ̀ wa, ina
lati ẹnu rẹ̀ wa si njonirun, ẹyín si nràn
nipasẹ rẹ̀.
10 O tẹ ori ọrun ba pẹlu, o si sọkalẹ;
okunkun biri-biri si mbẹ li atẹlẹsẹ rẹ̀.
11 O si gun ori kerubu, o si fò: a si ri i
lori iyẹ afẹfẹ.
12 O si fi okunkun se ibujoko yi ara
rẹ̀ ka, ati agbajọ omi, ani iṣududu awọ-
sanma.
13 Nipasẹ imọlẹ iwaju rẹ̀ ẹyin-iná ràn.
14 Oluwa san ãra lati ọrun wá, ọga-ogo
julọ si fọhùn rẹ̀.
15 O si ta ọfà, o si tú wọn ka; o kọ
mànà-mána, o si ṣẹ wọn.
16 Iṣàn ibu okun si fi ara hàn, ipilẹ aiye
fi ara hàn, nipa ibawi Oluwa, nipa fifún
ẽmi ihò imu rẹ̀.
17 O ranṣẹ lati oke wá, o mu mi; o fà
mi jade lati inu omi nla wá.
18 O gbà mi lọwọ ọta mi alagbara, lọwọ
awọn ti o korira mi: nitoripe nwọn li
agbara jù mi lọ.
19 Nwọn ṣaju mi li ọjọ ipọnju mi; ṣu-
gbọn Oluwa li alafẹhinti mi.
20 O si mu mi wá si àye nla: o gbà mi,
nitoriti inu rẹ̀ dùn si mi.
21 Oluwa san a fun mi gẹgẹ bi ododo
mi: o si san a fun mi gẹgẹ bi mimọ́ ọwọ́
mi.
22 Nitoripe emi pa ọ̀na Oluwa mọ, emi
kò si fi ìwa buburu yapa kuro lọdọ Ọlọrun
mi.
23 Nitoripe gbogbo idajọ rẹ̀ li o wà ni-
waju mi: ati niti ofin rẹ̀, emi kò si yapa
kuro ninu wọn.
24 Emi si wà ninu iwà-titọ si i, emi si
pa ara mi mọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ mi.
25 Oluwa si san fun mi gẹgẹ bi ododo
mi, gẹgẹ bi ìwa-mimọ́ mi niwaju rẹ̀.
26 Fun alãnu ni iwọ o fi ara rẹ hàn
li alãnu, ati fun ẹni-iduro-ṣinṣin li ododo
ni iwọ o fi ara rẹ hàn ni iduro-ṣinṣin li
ododo.
27 Fun oninu-funfun ni iwọ o fi ara rẹ
hàn ni funfun: ati fun ẹni-wiwọ ni iwọ o
fi ara rẹ hàn ni wiwọ.
28 Awọn enia ti o wà ninu iyà ni iwọ o
si gbàla: ṣugbọn oju rẹ wà lara awọn agbe-
raga, lati rẹ̀ wọn silẹ.
29 Nitori iwọ ni imọlẹ mi, Oluwa:
Oluwa yio si sọ okunkun mi di imọlẹ.
30 Nitori nipa rẹ li emi ti là arin ogun
kọja: nipa Ọlọrun mi emi ti fò odi kan.
31 Pipe li Ọlọrun li ọ̀na rẹ̀: ọ̀rọ Oluwa
li a ti dan wò: on si ni asà fun gbogbo
awọn ti o gbẹkẹle e.
32 Nitori tani iṣe Ọlọrun, bikoṣe Olu-
wa? tabi tani iṣe apáta, bikoṣe Ọlọrun
wa?
33 Ọlọrun alagbara li o fun mi li agbara,
o si sọ ọ̀na mi di titọ́.
34 O ṣe ẹsẹ mi bi ẹsẹ agbọnrin: o si mu
mi duro ni ibi giga mi.
35 O kọ ọwọ́ mi ni ogun jijà; tobẽ ti
apá mi fà ọrun idẹ.
36 Iwọ si ti fun mi li asà igbala rẹ;
irẹlẹ rẹ si ti sọ mi di nla.
37 Iwọ si sọ itẹlẹ mi di nla li abẹ mi;
tobẽ ti ẹsẹ mi kò fi yọ́.
38 Emi ti lepa awọn ọta mi, emi si ti
run wọn; emi kò pẹhinda titi emi fi run
wọn.
39 Emi ti pa wọn run, emi si ti fọ́ wọn,

Digitized by Google

nwọn kò si le dide mọ: nwọn ṣubu labẹ ẹsẹ mi.

40 Iwọ si ti fi agbara di mi li amure fun ijà: awọn ti o ti dide si mi ni iwọ si ti tẹ̀ li ori ba fun mi.

41 Iwọ si mu awọn ọta mi pẹhindà fun mi, emi si pa awọn ti o korira mi run.

42 Nwọn wò, ṣugbọn kò si ẹnikan lati gbà wọn; nwọn wò Oluwa, ṣugbọn kò da wọn lohùn.

43 Nigbana ni emi si gun wọn wẹwẹ bi erupẹ ilẹ, emi si tẹ̀ wọn mọlẹ bi ẹrẹ̀ ita, emi si tẹ wọn gbọrọ.

44 Iwọ si gbà mi kuro lọwọ ijà awọn enia mi, iwọ pa mi mọ ki emi ki o le ṣe olori awọn ajeji orilẹ-ède: awọn enia ti emi kò ti mọ̀ yio ma sìn mi.

45 Awọn alejo yio fi ẹ̀tan tẹriba fun mi: bi nwọn ba ti gbọ́ iró mi, nwọn o si gbọ́ ti emi.

46 Arẹ̀ yio mu awọn alejo, nwọn o si ma bẹ̀ru nibi kọ́lọfin wọn.

47 Oluwa mbẹ; olubukun si li apata mi: gbigbega si li Ọlọrun apata igbala mi.

48 Ọlọrun li ẹniti ngbẹsan mi, ati ẹniti nrẹ̀ awọn enia silẹ labẹ mi.

49 Ati ẹniti o gbà mi kuro lọwọ awọn ọta mi: iwọ si gbe mi soke ju awọn ti o dide si mi lọ: iwọ si gbà mi kuro lọwọ ọkọnrin ìwa agbara.

50 Nitorina emi o fi ọpẹ fun ọ. Oluwa, larin awọn ajeji orilẹ-ède: emi o si kọrin si orukọ rẹ.

51 On ni ile-iṣọ igbala fun ọba rẹ̀: o si fi ãnu hàn fun ẹni-ami-ororo rẹ̀; fun Dafidi, ati fun iru-ọmọ rẹ̀ titi lailai.

## ORI 23.

WỌNYI si li ọ̀rọ ikẹhin Dafidi. Dafidi ọmọ Jesse, ani ọkọnrin ti a ti gbega, ẹni-ami-ororo Ọlọrun Jakobu, ati olorin didùn Israeli wi pe,

2 Ẹmi Oluwa sọ ọ̀rọ nipa mi, ọ̀rọ rẹ̀ si mbẹ li ahọn mi.

3 Ọlọrun Israeli ní, Apata Israeli sọ fun mi pe, Ẹnikan ti nṣe alakoso enia lododo, ti nṣakoso ni ibẹru Ọlọrun.

4 Yio si dabi imọlẹ owurọ nigbati õrun ba là, owurọ ti kò ni ikũku, nigbati koriko tutu ba hù lati ilẹ wa nipa itanṣan lẹhin òjo.

5 Lõtọ ile mi kò ri bẹ niwaju Ọlọrun, ṣugbọn o ti ba mi da majẹmu ainipẹkun, ti a tunṣe ninu ohun gbogbo, ti a si pamọ: nitoripe gbogbo eyi ni igbala mi, ati gbogbo ifẹ mi, ile mi kò le ṣe ki o ma dagbà?

6 Ṣugbọn gbogbo awọn ọmọ Beliali yio dabi ẹgún ọ̀wọn ti a ṣatì, nitoripe a kò le fi ọwọ́ kó wọn.

7 Ṣugbọn ọkọnrin ti yio tọ́ wọn yio fi irin ati ọpa ọ̀kọ sagbàra yi ara rẹ̀ ka: nwọn o si jona lulu nibi kanna.

8 Wọnyi si li orukọ awọn ọkọnrin alagbara ti Dafidi ni: ẹniti o joko ni ibujoko Takmoni ni olori awọn balogun, on si ni Adino Esniti ti o pa ọdunrun enia lẹrinkan.

9 Ẹniti o tẹ̀le e ni Eleasari ọmọ Dodo ara Ahohi, ọkan ninu awọn alagbara ọkọnrin mẹta ti o wà pẹlu Dafidi, nigbati nwọn pe awọn Filistini ni ijà, awọn ti o kó ara wọn jọ si ibẹ lati jà, awọn ọmọkọnrin Israeli si ti lọ kuro:

10 On si dide, o si kọlù awọn Filistini titi ọwọ́ fi kún u, ọwọ́ rẹ̀ si lẹ̀ mọ idà: Oluwa si ṣiṣẹ igbala nla li ọjọ na; awọn enia si yipada lẹhin rẹ̀ lati ko ikogun.

11 Ẹniti o tẹ̀le e ni Samma ọmọ Agee ará Harari. Awọn Filistini si ko ara wọn jọ lati piyẹ, oko kan si wà nibẹ ti o kún fun ẹwẹ: awọn enia si sa kuro niwaju awọn Filistini.

12 O si duro lagbedemeji ilẹ na, o si gbà a silẹ, o si pa awọn Filistini: Oluwa si ṣe igbala nla kan.

13 Awọn mẹta ninu ọgbọ̀n olori si sọkalẹ, nwọn si tọ Dafidi wá li akoko ikore ninu iho Adullamu: ọ̀wọ́ awọn Filistini si do ni afonifoji Refaimu.

14 Dafidi si wà ninu odi, ibudo awọn Filistini si wà ni Betlehemu nigbana.

15 Dafidi si k'ongbẹ, o wi bayi pe, Tani yio fun mi mu ninu omi kanga ti mbẹ ni Betlehemu, eyi ti o wà ni ihà ẹnubode?

16 Awọn ọkọnrin alagbara mẹta si la ogun awọn Filistini lọ, nwọn si fa omi lati inu kanga Betlehemu wá, eyi ti o wà ni iha ẹnubode, nwọn si mu tọ Dafidi wá: on kò si fẹ mu ninu rẹ̀, ṣugbọn o tú u silẹ fun Oluwa.

17 On si wipe, Ki a ma ri, Oluwa, ti emi o fi ṣe eyi; ṣe eyi li ẹ̀jẹ awọn ọkọnrin ti o lọ ti awọn ti ẹmi wọn li ọwọ́? nitorina on kò si fẹ mu u. Nkan wọnyi li awọn ọkọnrin alagbara mẹtẹta yi ṣe.

18 Abiṣai, arakọnrin Joabu, ọmọ Seruia, on na ni pataki ninu awọn mẹta. On li o si gbe ọ̀kọ rẹ̀ soke si ọdurun enia, o si pa wọn, o si ni orukọ ninu awọn mẹtẹta.

19 Ọlọlajulọ li on iṣe ninu awọn mẹtẹta: o si jẹ olori fun wọn: ṣugbọn on kò to awọn mẹta iṣaju.

20 Benaiah, ọmọ Jehoiada, ọmọ akọni

ọkọnrin kan ti Kabséeli, ẹniti o pọ̀ ni iṣe agbara, on pa awọn ọmọ Arieli meji ti Moabu; o sọkalẹ pẹlu o si pa kiniun kan ninu iho lakoko sno.

21 O si pa ara Egipti kan, ọkọnrin ti o tó wò: ara Egipti na si ni ọ̀kọ kan li ọwọ́ rẹ̀: ṣugbọn on si sọkalẹ tọ̀ ọ lọ, ton ti ọ̀pá li ọwọ́, o si gba ọ̀kọ na lọwọ ara Egipti na, o si fi ọ̀kọ tirẹ̀ pa a.

22 Nkan wọnyi ni Benaia ọmọ Jehoiada ṣe, o si li orukọ ninu awọn ọkọnrin alagbara mẹta nì.

23 Ninu awọn ọgbọ̀n na, on ṣe ọlọlajulọ, ṣugbọn on kò to awọn mẹta ti iṣaju. Dafidi si fi i ṣe igbimọ̀ rẹ̀.

24 Asaheli arakọnrin Joabu si jasi ọkan ninu awọn ọgbọ̀n na; Elhanani ọmọ Dodo ti Betlehemu.

25 Ṣamma ara Harodi, Elika ara Harodi.

26 Helesi ara Palti, Ira ọmọ Ikkeṣi ara Tekoa.

27 Abieseri ara Anetoti, Mebunnai Huṣatiti.

28 Salmoni Ahohiti, Maharai ara Netofa,

29 Helebu ọmọ Baana, ara Netofa, Ittai ọmọ Ribai ti Gibea ti awọn ọmọ Benjamini,

30 Benaia ara Piratoni, Hiddai ti afonifoji,

31 Abialboni ara Arba Asmafeti Barhumiti,

32 Eliahba ara Saalboni, Jaṣeni Gisoniti, Jonatani,

33 Ṣamma Harariti, Ahiamu ọmọ Ṣarari Harariti,

34 Elifeleti ọmọ Ahasbai, ọmọ ara Maakha, Eliamu ọmọ Ahitofeli ara Giloni,

35 Hesrai ara Kermeli, Paari ara Arba,

36 Igali ọmọ Natani ti Soba, Bani ara Gadi,

37 Sekeli ara Ammoni, Nahari ara Beeroti, ẹniti o nru ihamọra Joabu ọmọ Seruia.

38 Ira ara Jattiri, Garebu ara Jattiri.

39 Uria ara Hitti: gbogbo wọn jẹ mẹtadilogoji.

## ORI 24.

IBINU Oluwa si ru si Israeli, o si tì Dafidi si wọn, pe, Lọ kà iye Israeli ati Juda.

2 Ọba si wi fun Joabu olori ogun, ti mbẹ lọdọ rẹ̀ pe, Lọ nisisiyi si gbogbo ẹyà Israeli lati Dani titi de Beerṣeba, ki ẹ si kà iye awọn enia, ki emi le mọ̀ iye awọn enia na.

3 Joabu si wi fun ọba pe, Ki Oluwa Ọlọrun rẹ ki o fi kún iye awọn enia na, iyekiye ki o wu ki wọn jẹ, li ọrọrún; oju oluwa mi ọba yio si ri i: ṣugbọn ẽtiṣe ti oluwa mi ọba fi fẹ nkan yi?

4 Ṣugbọn ọ̀rọ ọba si bori ti Joabu, ati ti awọn olori ogun. Joabu ati awọn olori ogun si jade lọ kuro niwaju ọba, lati lọ ika awọn enia Israeli.

5 Nwọn si kọja odo Jordani, nwọn si pagọ ni Aroeri, ni iha apá ọtún ilu ti o wà lagbedemeji afonifoji Gadi, ati si iha Jaseri:

6 Nwọn si wá si Gileadi, ati si ilẹ Tatimhodṣi; nwọn si wá si Dan-jaani ati yikakiri si Sidoni,

7 Nwọn si wá si ilu olodi Tire, ati si gbogbo ilu awọn Hifi, ati ti awọn ara Kenaani: nwọn si jade lọ siha gusu ti Juda, ani si Beerṣeba.

8 Nwọn si la gbogbo ilẹ na ja, nwọn si wá si Jerusalemu li opin oṣù kẹsan ati ogunjọ.

9 Joabu si fi iye ti awọn enia na jasi le ọba lọwọ: o si jẹ oji ọkẹ ọkọnrin alagbara ní Israeli, awọn onidà: awọn ọkọnrin Juda si jẹ ọkẹ mẹ̃dọgbọn enia.

10 Aiya Dafidi si jingiri lẹhin igbati o kà awọn enia na tan. Dafidi si wi fun Oluwa pe, Emi ṣẹ̀ gidigidi li eyi ti emi ṣe: ṣugbọn, emi bẹ̀ ọ, Oluwa, fi ẹ̀ṣẹ iranṣẹ rẹ jì i, nitoripe emi huwà aṣiwere gidigidi.

11 Dafidi si dide li owurọ, ọ̀rọ Oluwa si tọ Gadi wolĩ wá, ariran Dafidi, wipe,

12 Lọ, ki o si wi fun Dafidi pe, Bayi li Oluwa wi, emi fi nkan mẹta lọ̀ ọ; yàn ọkan ninu wọn, emi o si ṣe e si ọ.

13 Gadi si tọ Dafidi wá, o si bi i lere pe, Ki iyàn ọdun meje ki o tọ̀ ọ wá ni ilẹ rẹ bi? tabi ki iwọ ki o ma sá li oṣu mẹta niwaju awọn ọta rẹ, nigbati nwọn o ma le ọ? tabi ki arùn iparun ijọ mẹta ki o wá si ilẹ rẹ? rõ nisisiyi, ki o si mọ̀ èsi ti emi o mu pada tọ̀ ẹniti o rán mi.

14 Dafidi si wi fun Gadi pe, Iyọnu nla ba mi: jẹ ki a fi ara wa le Oluwa li ọwọ́; nitoripe ãnu rẹ̀ pọ̀: ki o má si ṣe fi mi le enia li ọwọ́.

15 Oluwa si rán arùn iparun si Israeli lati owurọ̀ titi de akoko ti a da: ẹgbã marundilogoji enia si kú ninu awọn enia na lati Dani titi fi de Beerṣeba.

16 Nigbati angeli na si nawọ́ rẹ̀ si Jerusalemu lati pa a run, Oluwa si kãnu nitori ibi na, o si sọ fun angeli ti npa awọn enia na run pe, O to: da ọwọ́ rẹ duro wayi. Angeli Oluwa na si wà nibi ipaka Arauna ara Jebusi.

17 Dafidi si wi fun Oluwa nigbati o ri

Digitized by Google

angeli ti nkọlu awọn enia pe, Wõ, emi ti
ṣẹ̀, emi si ti huwà buburu: ṣugbọn awọn
agutan wọnyi, kini nwọn ha ṣe? jẹ ki ọwọ́
rẹ, emi bẹ̀ ọ, ki o wà li ara mi, ati li ara
idile baba mi.
18 Gadi si tọ Dafidi wá li ọjọ na, o si wi
fun u pe, Goke, tẹ́ pẹpẹ kan fun Oluwa ni-
bi ipaka Arauna ara Jebusi.
19 Gẹgẹ bi ọ̀rọ Gadi, Dafidi si goke lọ bi
Oluwa ti pa a li aṣẹ.
20 Arauna si wò, o si ri ọba ati awọn
iranṣẹ rẹ̀ mbọ̀ wá ọdọ rẹ̀: Arauna si jade,
o si wolẹ niwaju ọba o si doju rẹ̀ bolẹ.
21 Arauna si wipe, Nitori kili oluwa mi
ọba ṣe tọ iranṣẹ rẹ̀ wá? Dafidi si dahùn
pe, Lati rà ibi ipaka nì lọwọ rẹ, lati tẹ́ pẹpẹ
kan fun Oluwa, ki arùn iparun ki o le da
li ara awọn enia na.
22 Arauna si wi fun Dafidi pe, Jẹ ki olu-
wa mi ọba ki o mu eyi ti o dara li oju rẹ̀,
ki o si fi i rubọ: wõ, malu niyi lati fi ṣe
ẹbọ sisun, ati ohun elo ipaka, ati ohun elo
miran ti malu fun igi.
23 Gbogbo nkan wọnyi ni Arauna fi fun
ọba, bi ọba. Arauna si wi fun ọba pe, Ki
Oluwa Ọlọrun rẹ ki o gbà ọrẹ rẹ.
24 Ọba si wi fun Arauna pe, Bẹ̃kọ;
ṣugbọn emi o rà a ni iye kan lọwọ rẹ, bi o
ti wù ki o ṣe; bẹ̃li emi kì yio fi eyiti emi
kò nawo fun, rú ẹbọ sisun si Oluwa Ọlọrun
mi. Dafidi si rà ibi ipaka na, ati awọn
malũ na li ãdọta ṣekeli fadaka.
25 Dafidi si tẹ́ pẹpẹ kan nibẹ si Oluwa,
o si rú ẹbọ sisun ati ti ilaja. Oluwa si gbọ́
ẹ̀bẹ fun ilẹ na, arùn na si da kuro ni
Israeli.

---

IWE IKINI

# AWỌN ỌBA.

## ORI 1.

DAFIDI ọba si di arugbo, ọjọ rẹ̀ si pọ̀;
nwọn si fi aṣọ bò o lara, ṣugbọn kò
mõru.
2 Awọn iranṣẹ rẹ̀ si wi fun u pe, Jẹ ki a
wá ọmọbirin kan, wundia, fun Oluwa mi
ọba: ki o si duro niwaju ọba, ki o si ṣikẹ́
rẹ̀, ki o si dubulẹ li õkan-aiya rẹ̀, oluwa
mi, ọba yio si mõru.
3 Nwọn si wá ọmọbirin arẹwà kan ka
gbogbo agbegbe Israeli, nwọn si ri Abiṣagi,
ara Ṣunemu, nwọn si mu u tọ̀ ọba wá.
4 Ọmọbirin na si ṣe arẹwà gidigidi, o si
nṣikẹ́ oba, o si nṣe iranṣe fun u; ṣugbọn
ọba kò si mọ̀ ọ.
5 Adonijah, ọmọ Haggiti, si gbe ara rẹ̀
ga, wipe, emi ni yio jọba: o si mura kẹkẹ́
ati awọn ẹlẹṣin ati ãdọta ọkọnrin lati sare
niwaju rẹ̀.
6 Baba rẹ̀ kò si bà a ninu jẹ ri, pe, Ẽṣe
ti iwọ fi ṣe bayi? on si ṣe enia ti o dara
gidigidi: iya rẹ̀ si bi i le Absalomu.
7 O si ba Joabu, ọmọ Seruiah, ati Abi-
atari, alufa gbèro: nwọn si nràn Adonijah
lọwọ.
8 Ṣugbọn Sadoku alufa, ati Benaiah,
ọmọ Jehoiada, ati Natani woli, ati Ṣimei,
ati Rei, ati awọn ọkọnrin alagbara ti mbẹ
lọdọ Dafidi, kò wà pẹlu Adonijah.
9 Adonijah si pa agutan ati malu ati
ẹran-ọ̀sin ti o sanra nibi okuta Soheleti, ti
mbẹ lẹba Enrogeli, o si pè gbogbo awọn
arakọnrin rẹ̀, awọn ọmọ ọba, ati gbogbo
ọkọnrin Juda, iranṣẹ ọba:
10 Ṣugbọn Natani, alufa, ati Benaiah
ati awọn ọkọnrin alagbara, ati Solomoni
arakọnrin rẹ̀ ni kò pè.
11 Natani si wi fun Batṣeba, iya Solo-
moni pe, Iwọ kò gbọ́ pe, Adonijah, ọmọ
Haggiti jọba, Dafidi, oluwa wa, kò si mọ́?
12 Nitorina, wá nisisiyi, emi bẹ̀ ọ, emi o
si fun ọ ni ìmọ, ki iwọ ki o le gbà ẹmi rẹ
là, ati ẹmi Solomoni ọmọ rẹ.
13 Lọ, ki o si tọ̀ Dafidi, oba lọ, ki o si
wi fun u pe, Ọba, oluwa mi, ṣe iwọ li o
bura fun ọmọ-ọdọ rẹ ọbirin, pe, nitõtọ
Solomoni, ọmọ rẹ, ni yio jọba lẹhin mi, on
ni o si joko lori itẹ mi? ẽṣe ti Adonijah fi
jọba?
14 Kiyesi i, bi iwọ ti mba ọba sọ̀rọ lọwọ,
emi o si tẹle ọ, emi o si wá ikún ọ̀rọ rẹ.

Digitized by Google

15 Batṣeba si tọ̀ oba lọ ni iyẹ̀wu: ọba si
gbó gidigidi: Abiṣagi, ara Ṣunemu, si nṣe
iranṣẹ fun ọba.
16 Batṣeba si tẹriba, o si wolẹ fun ọba.
Ọba si wipe, Kini iwọ nfẹ?
17 On si wi fun u pe, oluwa mi, iwọ fi
Oluwa Ọlọrun rẹ bura fun ọmọ-ọdọ rẹ obi-
rin pe, nitõtọ Solomoni, ọmọ rẹ, yio jọba
lẹhin mi, on o si joko lori itẹ mi.
18 Sa wò o, nisisiyi, Adonijah jọba; iwọ,
oluwa mi ọba, kò si mọ̀.
19 O si pa malu ati ẹran ti o li ọra, ati
agùtan li ọ̀pọlọpọ, o si pe gbogbo awọn ọmọ
ọba, ati Abiatari alufa, ati Joabu balogun:
ṣugbọn Solomoni iranṣẹ rẹ ni kò pè.
20 Ati iwọ, oluwa mi, ọba, oju gbogbo
Israeli mbẹ lara rẹ, ki iwọ ki o sọ fun wọn,
tani yio joko lori itẹ oluwa mi ọba lẹhin
rẹ̀?
21 Yio si ṣe, nigbati oluwa mi ọba ba
sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a o si kà emi ati
Solomoni ọmọ mi si ẹlẹṣẹ̀.
22 Si wò o, bi o si ti mba ọba sọ̀rọ lọwọ,
Natani woli si wọle.
23 Nwọn si sọ fun ọba pe, Wò o, Nata-
ni woli. Nigbati o si wá siwaju ọba, o
wolẹ̀, o si dojubolẹ.
24 Natani si wipe, oluwa mi, ọba! iwọ
ha wipe, Adonijah ni yio jọba lẹhin mi ati
pe, on o si joko lori itẹ mi bi?
25 Nitori o sọkalẹ lọ loni, o si pa malu
ati ẹran ọlọra, ati agùtan li ọ̀polọpọ, o si pè
gbogbo awọn ọmọ ọba, ati awọn balogun,
ati Abiatari alufa; si wò o, nwọn njẹ,
nwọn si nmu niwaju rẹ̀, nwọn si nwipe, Ki
Adonijah ọba ki o pẹ.
26 Ṣugbọn emi, emi iranṣẹ rẹ, ati Sado-
ku alufa, ati Benaiah ọmọ Jehoiada, ati
Solomoni, iranṣẹ rẹ, ni kò pè.
27 Nkan yi ti ọdọ oluwa mi ọba wá bi?
iwọ kò si fi ẹniti yio joko lori itẹ oluwa mi
ọba lẹhin rẹ̀ hàn iranṣẹ rẹ?
28 Dafidi, ọba si dahùn o si wipe, Ẹ pè
Batṣeba fun mi. On si wá siwaju ọba, o si
duro niwaju ọba,
29 Ọba si bura, o si wipe, Bi Oluwa ti
wà, ẹniti o ti rà ọkàn mi pada kuro ninu
gbogbo iṣẹ́.
30 Gẹgẹ bi mo ti fi Oluwa, Ọlọrun Isra-
eli bura fun ọ, wipe, Nitõtọ Solomoni, ọmọ
rẹ, yio jọba lẹhin mi, on o si joko lori itẹ
mi ni ipò mi, bẹ̃ni emi o ṣe loni yi dandan.
31 Batṣeba si foribalẹ, o si bọ̀wọ fun ọba,
o si wipe, Ki oluwa mi, Dafidi ọba ki o pẹ
titi lai.
32 Dafidi ọba wipe, Ẹ pè Sadoku alufa
fun mi, ata Natani woli, ati Benaiah ọmọ
Jehoiada. Nwọn si wá siwaju ọba.
33 Ọba si wi fun wọn pe, Ẹ mu awọn
iranṣẹ oluwa nyin, ki ẹ si mu ki Solomoni
ọmọ mi ki o gùn ibãka mi, ki ẹ si mu sọ-
kalẹ wá si Gihoni.
34 Ki ẹ si jẹ ki Sadoku, alufa, ati Na-
tani woli, fi ororo yàn a nibẹ̀ li ọba lori
Israeli: ki ẹ si fun fère, ki ẹ si wipe; Ki
Solomoni ọba ki o pẹ!
35 Ki ẹ si goke tọ̀ ọ lẹhin, ki o si wá, ki
o si joko lori itẹ mi; on o si jọba ni ipò
mi: emi si pa a laṣe lati jẹ olori Israeli ati
Juda.
36 Benaiah ọmọ Jehoiada, si da ọba
lohùn, o si wipe, Amin: Oluwa, Ọlọrun
ọba oluwa mi, wi bẹ̃ pẹlu.
37 Bi Oluwa ti wà pẹlu oluwa mi ọba,
gẹgẹ bẹ̃ni ki o wà pẹlu Solomoni, ki o si ṣe
itẹ rẹ̀ ki o pọ̀ jù itẹ oluwa mi, Dafidi ọba
lọ.
38 Sadoku alufa, ati Natani woli, ati
Benaiah, ọmọ Jehoiada, ati awọn ara Ke-
reti ati Peleti si sọkalẹ, nwọn si mu ki
Solomoni ki o gùn ibãka Dafidi ọba, nwọn
si mu u wá si Gihoni,
39 Sadoku alufa si mu iwo ororo lati inu
agọ, o si dà a si Solomoni lori; nwọn si
fun fèrẹ; gbogbo enia si wipe, Ki Solo-
moni ọba ki o pẹ.
40 Gbogbo enia si goke tọ̀ ọ lẹhin, awọn
enia si fun ipè, nwọn si yọ̀ ayọ̀ nlanla,
tobẹ̃ ti ilẹ mì fun iró wọn.
41 Ati Adonijah ati gbogbo awọn ti o
pè sọdọ rẹ̀ si gbọ́, nigbati nwọn jẹun tan,
Joabu si gbọ́ iró ipè o si wipe: eredi ariwo
ilu ti nrokẹkẹ yi?
42 Bi o si ti nsọ lọwọ, kiyesi i, Jonatani,
ọmọ Abiatari, alufa de; Adonijah si wi
fun u pe, Mã wolẹ̀; nitoripe alagbara
ọkọnrin ni iwọ, ati ẹniti nmu ihin-rere wá.
43 Jonatani si dahùn o si wi fun Adoni-
jah pe, Lõtọ ni, oluwa wa, Dafidi ọba, fi
Solomoni jọba.
44 Ọba si ti rán Sadoku alufa, ati Natani
woli, ati Benaiah, ọmọ Jehoiada, ati awọn
ara Kereti ati Peleti pẹlu rẹ̀, nwọn si ti mu
u ki o gùn ibãka ọba.
45 Sadoku, alufa ati Natani, woli si ti fi
ororo yàn a li ọba ni Gihoni: nwọn si fi
ayọ̀ goke lati ibẹ wá, tobẹ̃ ti ilu si nho.
Eyi ni ariwo ti ẹ ti gbọ́.
46 Solomoni si joko lori itẹ ijọba pẹlu.
47 Awọn iranṣẹ ọba si wá lati sure fun
oluwa wa, Dafidi ọba, pe, Ki Ọlọrun ki o
mu orukọ Solomoni ki o sàn jù orukọ rẹ lọ,

Digitized by Google

ki o si ṣe itẹ rẹ̀ ki o pọ̀ jù itẹ rẹ lọ. Ọba si
gbadura lori akete.
48 Ọba si wi bayi pẹlu, Olubukun li
Oluwa, Ọlọrun Israeli, ti o fun mi li ẹni-
kan ti o joko lori itẹ mi loni, oju mi si ri i.
49 Gbogbo awọn ti a pè, ti nwọn wà li
ọdọ Adonijah si bẹ̀ru, nwọn si dide, nwọn
si lọ olukuluku si ọ̀na rẹ̀.
50 Adonijah si bẹ̀ru Solomoni, o si dide,
o si lọ, o si di iwo pẹpẹ mu.
51 Nwon si wi fun Solomoni pe, Wò o,
Adonijah bẹ̀ru Solomoni ọba: si kiyesi i, o
di iwo pẹpẹ mu, o nwipe, Ki Solomoni ọba
ki o bura fun mi loni pe, On kì yio fi idà
pa iranṣẹ rẹ̀.
52 Solomoni si wipe, Bi o ba jẹ fi ara rẹ̀
si ọ̀wọ, irun ori rẹ̀ kan kì yio bọ́ silẹ: ṣu-
gbọn bi a ba ri buburu lọwọ rẹ̀, on o kú.
53 Solomoni ọba si ranṣẹ, nwọn mu u
sọkalẹ lori pẹpẹ. On si wá, o si foribalẹ̀
fun Solomoni ọba: Solomoni si wi fun u
pe, Mã lọ ile rẹ.

## ORI 2.

ỌJỌ Dafidi si sunmọ etile ti yio kú: o si
paṣẹ fun Solomoni, ọmọ rẹ̀ pe:
2 Emi nlọ si ọ̀na gbogbo aiye: nitorina
mu ara rẹ le, ki o si fi ara rẹ̀ hàn bi ọkọn-
rin.
3 Ki o si pa ilana Oluwa, Ọlọrun rẹ mọ,
lati ma rin li ọ̀na rẹ̀, lati pa aṣẹ rẹ̀ mọ ati
ofin rẹ̀, ati idajọ rẹ̀, ati ẹri rẹ̀ gẹgẹ bi a ti
kọ ọ ni ofin Mose, ki iwọ ki o lè ma pọ̀ si i
ni ohun gbogbo ti iwọ o ṣe, ati nibikibi ti
iwọ ba yi ara rẹ si.
4 Ki Oluwa ki o le mu ọ̀rọ rẹ̀ duro ti o
ti sọ niti emi pe: Bi awọn ọmọ rẹ ba kiye-
si ọ̀na wọn, lati mã fi gbogbo aiya wọn, ati
gbogbo ọkàn wọn, rìn niwaju mi li otitọ,
(o wipe), a kì yio fẹ ọkọnrin kan kù fun ọ
lori itẹ Israeli.
5 Iwọ si mọ̀ pẹlu, ohun ti Joabu, ọmọ
Seruiah, ṣe si mi, ati ohun ti o ṣe si balo-
gun meji ninu awọn ọgagun Israeli, si
Abneri, ọmọ Neri, ati si Amasa, ọmọ Jeteri,
o si pa wọn, o si ta ẹ̀jẹ ogun silẹ li alafia, o
si fi ẹ̀jẹ ogun si ara àmure rẹ̀ ti mbẹ li ẹgbẹ
rẹ̀, ati si ara salubata rẹ̀ ti mbẹ li ẹsẹ rẹ̀.
6 Nitorina, ki o ṣe gẹgẹ bi ọgbọ́n rẹ, ki
o má si jẹ ki ewu ori rẹ̀ ki o sọkalẹ lọ si
isa-okú li alafia.
7 Ṣugbọn ki o ṣe ore fun awọn ọmọ Bar-
sillai, ara Gileadi, ki o si jẹ ki nwọn ki o
wà ninu awọn ti o jẹun lori tabili rẹ: ni-
tori bẹ̃ni nwọn ṣe tọ̀ mi wá nigbati mo sá
kuro niwaju Absalomu, arakọnrin rẹ.
8 Si wò o, Ṣimei, ọmọ Gera, ẹyà Ben-
jamini ti Bahurimu, wà pelu rẹ ti o bú mi
ni ẽbu ti o burujù, li ọjọ ti mo lọ si Ma-
hanaimu: ṣugbọn o sọkalẹ wá pade mi ni
Jordani, mo si fi Oluwa bura fun u pe, Emi
kì yio fi idà pa ọ.
9 Ṣugbọn nisisiyi, màṣe jẹ ki o ṣe alaiji-
ya, nitori ọlọgbọ́n enia ni iwọ, iwọ si mọ̀
ohun ti iwọ o ṣe si i; ṣugbọn ewú ori rẹ̀ ni
ki o mu sọkalẹ pẹlu ẹ̀jẹ sinu isa-okú.
10 Dafidi si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a si
sin i ni ilu Dafidi.
11 Ọjọ ti Dafidi jọba lori Israeli jẹ ogoji
ọdun: ni Hebroni o jọba li ọdun meje, ni
Jerusalemu o si jọba li ọdun mẹtalelọgbọn.
12 Solomoni si joko lori itẹ Dafidi baba
rẹ̀; a si fi idi ijọba rẹ̀ kalẹ gidigidi.
13 Adonijah, ọmọ Haggiti si tọ Batṣeba,
iya Solomoni wá, Batṣeba si wipe; Alafia
li o ba wá bi? On si wipe, alafia ni.
14 On si wipe, emi ni ọ̀rọ kan ba ọ sọ.
On si wipe, Mã wi:
15 On si wipe, Iwọ mọ̀ pe, ijọba na ti
emi ni ri, ati pe, gbogbo Israeli li o fi oju
wọn si mi lara pe, emi ni o jọba: ṣugbọn
ijọba na si yí, o si di ti arakọnrin mi; ni-
tori tirẹ̀ ni lati ọwọ́ Oluwa wá.
16 Nisisiyi, ibere kan ni mo wá bere
lọwọ rẹ, máṣe dù mi: O si wi fun u pe,
Mã wi.
17 O si wi pe, Mo bẹ ọ, sọ fun Solomoni
ọba (nitori kì yio dù ọ,) ki o fun mi ni
Abiṣagi, ara Ṣunemu li aya.
18 Batṣeba si wipe, o dara; emi o ba ọba
sọrọ nitori rẹ.
19 Batṣeba si tọ Solomoni ọba lọ, lati
sọ fun u nitori Adonijah. Ọba si dide lati
pade rẹ̀, o si tẹ ara rẹ̀ ba fun u, o si joko
lori itẹ́ rẹ̀ o si tẹ́ itẹ fun iya ọba, on si joko
lọwọ ọtun rẹ̀.
20 On si wipe, Ibere kekere kan li emi
ni ibere lọwọ rẹ; máṣe dù mi. On si wipe,
mã tọrọ, iya mi; nitoriti emi kì yio dù ọ.
21 On si wipe, jẹ ki a fi Abiṣagi, ara
Ṣunemu, fun Adonijah, arakọnrin rẹ, li
aya.
22 Solomoni ọba si dahùn, o si wi fun
iya rẹ̀ pe, Ẽṣe ti iwọ fi mbere Abiṣagi, ara
Ṣunemu, fun Adonijah, kuku bere ijọba
fun u pẹlu; nitori ẹgbọ́n mi ni iṣe; fun on
pãpa, ati fun Abiatari, alufa, ati fun Joabu,
ọmọ Seruiah.
23 Solomoni, ọba si fi Oluwa bura pe,
Bayi ni ki Ọlọrun ki o ṣe si mi, ati jubẽ
pẹlu, nitori Adonijah sọ̀rọ yi si ẹmi ara rẹ̀.
24 Ati nisisiyi bi Oluwa ti wà, ti o ti fi

Digitized by Google

idi mi mulẹ̀, ti o si mu mi joko lori itẹ́ baba
mi, ti o si ti kọ́ ile fun mi, gẹgẹ bi o ti wi,
loni ni a o pa Adonijah.
25 Solomoni, ọba si rán Benaiah, ọmọ
Jehoiada, o si kọlu u, o si kú.
26 Ati fun Abiatari, alufa, ọba wipe, Lọ
si Anatoti, si oko rẹ; nitori iwọ yẹ si ikú:
ṣugbọn loni emi kì yio pa ọ, nitori iwọ li o
ti ngbe apoti Oluwa Ọlọrun niwaju Dafidi
baba mi, ati nitori iwọ ti jẹ ninu gbogbo
iyà ti baba mi ti jẹ.
27 Solomoni si le Abiatari kuro ninu iṣẹ
alufa Oluwa; ki o le mu ọ̀rọ Oluwa ṣẹ, ti o
ti sọ nipa ile Eli ni Ṣilo.
28 Ihin si de ọdọ Joabu: nitori Joabu ti
tọ̀ Adonijah lẹhin, ṣugbọn kò tọ̀ Absalomu
lẹhin: Joabu si sá sinu agọ Oluwa, o si di
iwo pẹpẹ mu.
29 A si sọ fun Solomoni ọba pe, Joabu
ti sá sinu agọ Oluwa; si wò o, o sunmọ
pẹpẹ, Solomoni si rán Benaiah, ọmọ Je-
hoiada, pe, Lọ, ki o si kọlù u.
30 Benaiah si wá sinu agọ Oluwa, o si
wi fun u pe, Bayi li ọba wi, pe, Jade wá.
On si wipe, Bẹ̃kọ; ṣugbọn nihinyi li emi
o kú. Benaiah si mu èsi fun ọba wá pe,
Bayi ni Joabu wi, bayi ni o si dá mi lohùn.
31 Ọba si wi fun u pe, Ṣe gẹgẹ bi o ti wi
ki o si kọlù u, ki o si sin i, ki iwọ ki o le mu
ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ kuro lọdọ mi ati kuro lọdọ ile
baba mi, ti Joabu ti ta silẹ.
32 Oluwa yio si yi ẹ̀jẹ rẹ̀ pada sori rẹ̀,
nitoriti o kọlù ọkọnrin meji ti o ṣe olododo,
ti o sàn jù ontikararẹ̀ lọ, o si fi idà pa wọn.
Dafidi baba mi kò si mọ̀, ani, Abneri, ọmọ
Neri, olori ogun, ati Amasa, ọmọ Jeteri,
olori ogun Juda.
33 Ẹjẹ wọn yio si pada sori Joabu, ati
sori iru-ọmọ rẹ̀ lailai: ṣugbọn si Dafidi ati
si iru-ọmọ rẹ̀, ati si ile rẹ̀, ati si itẹ̀ rẹ̀,
alafia yio wà lati ọdọ Oluwa wá.
34 Benaiah, ọmọ Jehoiada, si goke, o si
kọlù u, o si pa a: a si sin i ni ile rẹ̀ li
aginju.
35 Ọba si fi Benaiah, ọmọ Jehoiada, jẹ
olori-ogun ni ipò rẹ̀, ati Sadoku alufa ni
ọba fi si ipò Abiatari.
36 Ọba si ranṣẹ, o si pe Ṣimei, o si wi
fun u pe, Kọ́ ile fun ara rẹ ni Jerusalemu,
ki o si ma gbe ibẹ̀, ki o má si ṣe jade lati
ibẹ lọ si ibikibi.
37 Yio si ṣe li ọjọ ti iwọ ba jade, ti iwọ
ba si kọja odò Kidroni, ki iwọ mọ̀ dajudaju
pe, Kikú ni iwọ o kú; ẹ̀jẹ rẹ yio wà lori
ara rẹ.
38 Ṣimei si wi fun ọba pe, Ọrọ na dara,
gẹgẹ bi oluwa mi ọba ti wi, bẹ̃ gẹgẹ ni
iranṣẹ rẹ yio ṣe. Ṣimei si gbe Jerusalemu
li ọjọ pupọ.
39 O si ṣe lẹhin ọdun mẹta, awọn ọmọ-
ọdọ Ṣimei meji si lọ sọdọ Akiṣi ọmọ Maaka,
ọba Gati. Nwọn si rò fun Ṣimei pe, Wo
o, awọn ọmọ-ọdọ rẹ mbẹ ni Gati.
40 Ṣimei si dide, o si di kẹtẹkẹtẹ ni gãri,
o si lọ, o si mu awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ bọ̀ lati
Gati.
41 A si rò fun Solomoni pe, Ṣimei, ti lọ
lati Jerusalemu si Gati, o si pada bọ̀.
42 Ọba si ranṣẹ, o si pè Ṣimei, o si wi
fun u pe, emi kò ti mu ọ fi Oluwa bura,
emi kò si ti fi ọ ṣe ẹlẹri, pe, Li ọjọ ti iwọ
ba jade, ti iwọ ba si rin jade lọ nibikibi, ki
iwọ ki o mọ̀ dajudaju pe, kikú ni iwọ o
kú? iwọ si wi fun mi pe, Ọrọ na ti mo gbọ́,
o dara.
43 Ẽ si ti ṣe ti iwọ kò pa ibura Oluwa
mọ, ati aṣẹ ti mo pa fun ọ?
44 Ọba si wi fun Ṣimei pe, Iwọ mọ̀ gbo-
gbo buburu ti ọkàn rẹ njẹ ọ lẹri, ti iwọ ti
ṣe si Dafidi, baba mi: Oluwa yio si yi
buburu rẹ si ori ara rẹ.
45 A o si bukun Solomoni ọba, a o si fi
idi itẹ́ Dafidi mulẹ niwaju Oluwa lailai.
46 Ọba si paṣẹ fun Benaiah ọmọ Jehoi-
ada, o si jade lọ, o si kọlù u, o si kú. A
si fi idi ijọba mulẹ li ọwọ́ Solomoni.

## ORI 3.

SOLOMONI si ba Farao ọba Egipti da
ana, o si gbe ọmọbirin Farao ni iyawo,
o si mu u wá si ilu Dafidi, titi o fi pari iṣẹ
ile rẹ̀, ati ile Oluwa, ati odi Jerusalemu
yika.
2 Kiki pe, awọn enia nrubọ ni ibi giga,
nitori a kò ti ikọ́ ile kan fun orukọ Oluwa,
titi di ọjọ wọnnì.
3 Solomoni si fẹ Oluwa, o si nrin nipa
aṣẹ Dafidi baba rẹ̀: ṣugbọn kiki pe, o
nrubọ, o si nfi turari jona ni ibi-giga.
4 Ọba si lọ si Gibeoni lati rubọ nibẹ;
nitori ibẹ ni ibi-giga nlanla: ẹgbẹrun ọrẹ
ẹbọ-sisun ni Solomoni ru lori pẹpẹ na.
5 Ni Gibeoni ni Oluwa fi ara rẹ̀ hàn Solo-
moni loju alá li oru: Ọlọrun si wipe, Bère
ohun ti emi o fi fun ọ.
6 Solomoni si wipe, Iwọ ti ṣe ore nla
fun iranṣẹ rẹ, Dafidi baba mi, gẹgẹ bi o ti
rin niwaju rẹ li otitọ ati li ododo, ati ni
iduro-ṣinṣin ọkàn pẹlu rẹ, iwọ si pa ore nla
yi mọ fun u lati fun u li ọmọkonrin ti o
joko lori itẹ rẹ̀, gẹgẹ bi o ti ri loni yi.
7 Njẹ nisisiyi, Oluwa Ọlọrun mi, iwọ ti

Digitized by Google

fi iranṣẹ rẹ jẹ ọba ni ipo Dafidi, baba mi:
ati emi, ọmọ kekere ni mi, emi kò si mọ̀
jijade ati wiwọle.
8 Iranṣẹ rẹ si mbẹ lãrin awọn enia rẹ ti
iwọ ti yàn, enia pupọ, ti a kò le moye, ti a
kò si lè kà fun ọ̀pọlọpọ.
9 Nitorina, fi ọkàn imoye fun iranṣẹ rẹ
lati ṣe idajọ awọn enia rẹ, lati mọ̀ iyatọ
rere ati buburu; nitori tali o le ṣe idajọ
awọn enia rẹ yi ti o pọ̀ to yi?
10 Ọrọ na si dara loju Oluwa, nitoriti
Solomoni bère nkan yi.
11 Ọlọrun si wi fun u pe, Nitoriti iwọ
bère nkan yi, ti iwọ kò si bère ẹmi gigun
fun ara rẹ, bẽni iwọ kò bère ọlá fun ara rẹ,
bẽni iwọ kò bère ẹmi awọn ọta rẹ; ṣugbọn
iwọ bère oye fun ara rẹ lati mọ̀ ẹjọ-idá;
12 Wò o, emi ti ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ, wò o,
emi fun ọ ni ọkàn ọgbọ́n ati imoye; tobẽ
ti kò ti isi ẹnikan ti o dabi rẹ ṣãju rẹ, bẽni
lẹhin rẹ ẹnikan kì yio dide ti yio dabi rẹ.
13 Ati eyiti iwọ kò bere, emi o fun ọ
pẹlu, ati ọrọ̀ ati ọlá: tobẽ ti kì yio si ọkan
ninu awọn ọba ti yio dabi rẹ.
14 Bi iwọ o ba si rìn ni ọ̀na mi lati pa
ṣọ ati ofin mi mọ, gẹgẹ bi Dafidi baba rẹ
i rìn, emi o si sún ọjọ rẹ siwaju.
15 Solomoni si jí; si wò o, alá ni. On
wá si Jerusalemu, o si duro niwaju apoti
ajẹmu Oluwa, o si rubọ ọrẹ sisun, o si ru
ọ-alafia, o si se àse fun gbogbo awọn
anṣẹ rẹ̀.
16 Nigbana ni obirin meji, ti iṣe àgbere,
sọdọ ọba, nwọn si duro niwaju rẹ̀.
17 Ọkan ninu wọn si wipe, Jọwọ, oluwa
, emi ati obirin yi ngbe ile kan; emi si
ọmọ ni ile pẹlu rẹ̀.
18 O si ṣe ni ọjọ kẹta lẹhin igbati mo
ọ tan, obirin yi si bimọ pẹlu: awa si
ọ ngbé pọ: kò si si alejo pẹlu wa ni
bikoṣe awa mejeji ni ile.
19 Ọmọ obirin yi si kú li oru; nitoriti o
le e.
20 O si dide li ọ̀ganjọ, o si gbe ọmọ mi
iha mi, nigbati iranṣẹ-birin rẹ sun, o
ẹ si aiya rẹ̀, o si tẹ́ okú ọmọ tirẹ̀ si
mi.
Mo si dide li owurọ lati fi ọmú fun
mi, si wò o, o ti kú: ṣugbọn nigbati
ò o fin li owurọ̀, si wò o, kì iṣe ọmọ
mo bí.
Obirin keji si wipe, Bẹ̃kọ; ṣugbọn
ãye ni ọmọ mi, eyi okú li ọmọ rẹ, eyi
e, Bẹ̃kọ; ṣugbọn eyi okú li ọmọ rẹ,
ãye si li ọmọ mi. Bayi ni nwọn nsọ
ọba.
23 Ọba si wipe, Ọkan wipe, eyi li ọmọ
mi ti o wà lãye, ati okú li ọmọ rẹ; ekeji
si wipe, Bẹ̃kọ; ṣugbọn eyi okú li ọmọ rẹ,
eyi alãye li ọmọ mi.
24 Ọba si wipe, Ẹ mu idà fun mi wá.
Nwọn si mu idà wá siwaju ọba.
25 Ọba si wipe, Ẹ là eyi alãye ọmọ si
meji, ki ẹ si mu idaji fun ọkan ati idaji
fun ekeji.
26 Obirin ti eyi alãye ọmọ iṣe tirẹ̀ si wi
fun ọba, nitori ti inu rẹ̀ yọ́ si ọmọ rẹ̀, o si
wipe, Jọwọ, oluwa mi, ẹ fun u ni eyi alãye
ọmọ, ki a máṣe pa a rara. Ṣugbọn eyi
ekeji si wipe, kì yio jẹ temi tabi tirẹ, ẹ
là a.
27 Ọba si dahùn o si wipe, ẹ fi alãye
ọmọ fun u, ki ẹ má si ṣe pa a: on ni iya rẹ̀.
28 Gbogbo Israeli si gbọ́ idajọ ti ọba ṣe;
nwọn si bẹ̀ru niwaju ọba: nitoriti nwọn ri
i pe, ọgbọ́n Ọlọrun wà ninu rẹ̀, lati ṣe
idajọ.

## ORI 4.

SOLOMONI ọba si jẹ ọba lori gbogbo
Israeli.
2 Awọn wọnyi ni awọn ijoye ti o ni;
Asariah, ọmọ Sadoku alufa,
3 Elihorefu ati Ahiah, awọn ọmọ Ṣiṣa
li akọwe, Jehoṣafati ọmọ Ahiludi li akọwe
ilu.
4 Ati Benaiah, ọmọ Jehoiada, li olori-
ogun: ati Sadoku ati Abiatari ni awọn
alufa:
5 Ati Asariah, ọmọ Natani, li olori
awọn ọgagun: Sabudu, ọmọ Natani, alufa,
si ni ọrẹ ọba:
6 Ati Ahiṣari li o ṣe olori agbo-ile: ati
Adoniramu, ọmọ Abda li o nṣe olori iṣẹ-
irú.
7 Solomoni si ni ijoye mejila lori gbogbo
Israeli, ti o npèse onjẹ fun ọba ati agbo-ile
rẹ̀; olukulùku li oṣu tirẹ̀ li ọdun ni npese.
8 Orukọ wọn si ni wọnyi: Benhuri li
oke Efraimu.
9 Bendekari ni Makasi, ati ni Ṣaal-bimu
ati Betṣemeṣi, ati Elonibethanani:
10 Benhesedi, ni Aruboti; tirẹ̀ ni Soko
iṣe ati gbogbo ilẹ Heferi:
11 Ọmọ Abinadabu, ni gbogbo agbègbe
Dori: ti o ni Tafati, ọmọbirin Solomoni,
li aya.
12 Baana ọmọ Ahiludi, tirẹ̀ ni Taanaki
iṣe, ati Megiddo, ati gbogbo Betṣeani ti
mbẹ niha Sartana nisalẹ Jesreeli, lati
Betṣeani de Abelmehola, ani titi de ibi ti
mbẹ ni ikọja Jokneamu;



Digitized by Google

13 Ọmọ Geberi ni Ramoti-Gileadi; tirẹ̀
ni awọn ileto Jairi, ọmọ Manasse, ti mbẹ
ni Gileadi; tirẹ̀ si ni apa Argobu, ti mbẹ
ni Baṣani, ọgọta ilu ti o tobi, ti o li odi ati
ọpa-idabu idẹ.
14 Ahinadabu, ọmọ Iddo, li o ni Mahanaimu.
15 Ahimaasi wà ni Naftali; on pẹlu li o
ni Basmati, ọmọbirin Solomoni, li aya.
16 Baana, ọmọ Huṣai wà ni Aṣeri ati ni
Aloti.
17 Jehoṣafati, ọmọ Paruha, ni Issakari:
18 Ṣimei, ọmọ Ela, ni Benjamini.
19 Geberi, ọmọ Uri wà ni ilẹ Gileadi
ni ilẹ Sihoni, ọba awọn ara Amori, ati Ogu,
ọba Baṣani: ijoye kan li o si wà ni ilẹ na.
20 Juda ati Israeli pọ̀ gẹgẹ bi iyanrin ti
mbẹ li eti okun ni ọ̀pọlọpọ, nwọn njẹ,
nwọn si nmu, nwọn si nṣe ariya.
21 Solomoni si jọba lori gbogbo awọn
ọba lati odò titi de ilẹ awọn ara Filistia,
ati titi de eti ilẹ Egipti: nwọn nmu ọrẹ
wá, nwọn si nsìn Solomoni ni gbogbo ọjọ
aiye rẹ̀.
22 Onjẹ Solomoni fun ijọ kan jasi ọgbọ̀n
iyẹ̀fun kikunna ati ọgọta oṣuwọn iyẹ̀fun iru
miran.
23 Malu mẹwa ti o sanra, ati ogún malu
lati inu papa wá, ati ọgọrun agutan, laika
agbọ̀nrin, ati egbin, ati ogbúgbu, ati ẹiyẹ
ti o sanra.
24 Nitori on li o ṣe alaṣẹ lori gbogbo
agbègbe ni ihà ihín odò, lati Tifsa titi de
Gasa, lori gbogbo awọn ọba ni ihà ihín
odò: o si ni alafia ni iha gbogbo yi i
kakiri.
25 Juda ati Israeli ngbe li alafia, olukuluku
labẹ àjara rẹ̀ ati labẹ igi ọpọtọ́ rẹ̀, lati
Dani titi de Beerṣeba, ni gbogbo ọjọ Solomoni.
26 Solomoni si ni ẹgbãji ile-ẹṣin fun
kẹkẹ́ rẹ̀, ati ẹgbãfa ẹlẹṣin.
27 Awọn ijoye na si pesè onjẹ fun Solomoni
ọba, ati fun gbogbo awọn ti o wá sibi
tabili Solomoni ọba, olukuluku li oṣu tirẹ̀:
nwọn kò fẹ nkankan kù.
28 Ọkà barle pẹlu, ati koriko fun ẹṣin
ati fun ẹṣin sisare ni nwọn mu wá sibiti o
gbe wà, olukuluku gẹgẹ bi ilana tirẹ̀.
29 Ọlọrun si fun Solomoni li ọgbọ́n ati
oye li ọ̀pọlọpọ, ati oye gbigboro, gẹgẹ bi
iyanrin ti o wà leti okun.
30 Ọgbọ́n Solomoni si bori ọgbọ́n gbogbo
awọn ọmọ ila-õrun, ati gbogbo ọgbọ́n
Egipti.
31 On si gbọ́n jù gbogbo enia; jù Etani,
ara Esra, ati Hemani, ati Kalkoli, ati
Dara, awọn ọmọ Maholi: okiki rẹ̀ si kàn
ni gbogbo orilẹ-ède yika.
32 O si pa ẹgbẹdọgbọn owe: orin rẹ̀ si
jẹ ẹgbẹrun o le marun.
33 O si sọ̀rọ ti igi, lati kedari ti mbẹ ni
Lebanoni, ani titi de hissopu ti nhu lara
ogiri: o si sọ̀ ti ẹranko pẹlu, ati ti ẹiyẹ, ati
ohun ti nrako, ati ti ẹja.
34 Ẹni pupọ si wá lati gbogbo orilẹ-ède
lati gbọ́ ọgbọ́n Solomoni; ani lati ọdọ gbogbo
awọn ọba aiye, ti o gburo ọgbọ́n rẹ̀.

## ORI 5.

HIRAMU, ọba Tire, si rán awọn iranṣẹ
rẹ̀ si Solomoni; nitoriti o ti gbọ́ pe, a
ti fi ororo yàn a li ọba ni ipò baba rẹ̀: nitori
Hiramu ti fẹràn Dafidi li ọjọ rẹ̀ gbogbo.
2 Solomoni si ranṣẹ si Hiramu wipe,
3 Iwọ mọ̀ bi Dafidi, baba mi, kò ti le kọ́
ile fun orukọ Oluwa Ọlọrun rẹ̀ nitori ogun
ti o wà yi i ka kiri, titi Oluwa fi fi wọn
sabẹ atẹlẹsẹ rẹ̀.
4 Ṣugbọn nisisiyi Oluwa Ọlọrun mi ti
fun mi ni isimi niha gbogbo, bẹ̃ni kò si si
ọta tabi ibi kan ti o ṣẹ̀.
5 Si kiye si i, mo gbèro lati kọ́ ile kan
fun orukọ Oluwa Ọlọrun mi, gẹgẹ bi Oluwa
ti sọ fun Dafidi, baba mi pe, Ọmọ rẹ,
ti emi o gbe kà ori itẹ́ rẹ ni ipò rẹ, on ni
yio kọ́ ile na fun orukọ mi.
6 Njẹ nisisiyi, paṣẹ ki nwọn ki o ke igi
kedari fun mi lati Lebanoni wá, awọn ọmọọdọ
mi yio si wà pẹlu awọn ọmọ-ọdọ rẹ,
iwọ ni emi o si sanwo ọyà awọn ọmọ-ọdọ
rẹ fun, gẹgẹ bi gbogbo eyi ti iwọ o wi: nitoriti
iwọ mọ̀ pe, kò si ẹnikan ninu wa ti
o mọ̀ bi a ti ike igi bi awọn ara Sidoni.
7 O si ṣe, nigbati Hiramu gbọ́ ọ̀rọ Solomoni,
o yọ̀ pipọ, o si wipe, Olubukún li
Oluwa loni, ti o fun Dafidi ni ọmọ ọlọgbọ́n
lori awọn enia pupọ yi.
8 Hiramu si ranṣẹ si Solomoni pe, Emi
ti gbọ́ eyi ti iwọ ránṣẹ si mi, emi o ṣe gbogbo
ifẹ rẹ niti igi kedari ati niti igi firi.
9 Awọn ọmọ ọdọ mi yio mu igi na ṣokalẹ
lati Lebanoni wá si okun: emi o si fi
wọn ṣọwọ si ọ ni fifó li omi okun titi de ibi
ti iwọ o nà ika si fun mi, emi o si mu ki
nwọn ki o ko wọn sibẹ, iwọ o si ko wọn
lọ: iwọ o si ṣe ifẹ mi, lati fi onjẹ fun ile
mi.
10 Bẹ̃ni Hiramu fun Solomoni ni igi
kedari ati igi firi gẹgẹ bi gbogbo ifẹ rẹ̀.
11 Solomoni si fun Hiramu ni ẹgbãwa

Digitized by Google

oṣuwọ̀n ọkà ni onjẹ fun ile rẹ̀, ati ogún
oṣuwọ̀n ororo daradara; bẽni Solomoni nfi
fun Hiramu li ọdọdun.
12 Oluwa si fun Solomoni li ọgbọ́n gẹgẹ
bi o ti wi fun u: alafia si wà lãrin Hiramu
ati Solomoni; awọn mejiji si ṣe adehùn.
13 Solomoni ọba, si ṣà asìnrú enia jọ ni
gbogbo Israeli; awọn alasìnru na jẹ ẹgbã
mẹdogun enia.
14 O si rán wọn lọ si Lebanoni, ẹgbarun
loṣoṣu, li ọwọ́-ọwọ; nwọn wà ni Lebanoni
loṣu kan, nwọn a si gbe ile li oṣu meji:
Adoniramu li o si ṣe olori awọn alasìnru
na.
15 Solomoni si ni ẹgbã marundilogoji
enia ti nru ẹrù, ọkẹ mẹrin gbẹnagbẹna lori
oke;
16 Laikà awọn ijoye ninu awọn ti a fi ṣe
olori iṣẹ Solomoni, ẹgbẹrindilogun o le
ọgọrun enia, ti o nṣe alaṣẹ awọn enia ti
nṣiṣẹ na.
17 Ọba si paṣẹ, nwọn si mu okuta wá,
okuta iyebiye, ati okuta gbígbẹ lati fi ipilẹ
ile na le ilẹ.
18 Awọn akọle Solomoni, ati awọn akọle
Hiramu si gbẹ́ wọn, ati awọn ara Gebali:
awọn si pèse igi ati okuta lati kọ́ ile na.

## ORI 6.

O SI ṣe, ni ọrinlenirinwo ọdun, lẹhin
igbati awọn ọmọ Israeli jade kuro ni
Egipti, li lọdun kẹrin ijọba Solomoni
lori Israeli, li oṣu Sifi ti iṣe oṣu keji, li o
bẹrẹ si ikọ́ ile fun Oluwa.
2 Ile na ti Solomoni ọba kọ́ fun Oluwa,
gigun rẹ̀ jẹ ọgọta igbọnwọ, ibú rẹ̀, ogun
igbọnwọ, ati giga rẹ̀, ọgbọn igbọnwọ.
3 Ati ọ̀dẹdẹ niwaju tempili ile na, ogún
igbọnwọ ni gigùn rẹ̀, gẹgẹ bi ibú ile na:
igbọnwọ mẹwa si ni ibú rẹ̀ niwaju ile na.
4 Ati fun ile na ni a ṣe ferese fun sise.
5 Lara ogiri ile na li o bù yàra yika;
ti tempili, ati ibi-mimọ́-julọ, li o si ṣe
yàra yika.
6 Yara isalẹ, igbọnwọ marun ni gbigbòro,
ti ãrin, igbọnwọ mẹfa ni gbigbòro rẹ̀,
ti ẹkẹta, igbọnwọ meje ni gbigbòro rẹ̀,
nitori lode ogiri ile na li o dín igbọnwọ
kan kakiri, ki igi-àja ki o má ba wọ inu
ogiri ile na.
7 Ile na, nigbati a nkọ́ ọ, okuta ti a ti
ṣe ni ilẹ ki a to mu u wá ibẹ li a fi kọ́ ọ,
tobẹ̃ ti a kò si gburo mataka, tabi ãke, tabi
ohun-elo irin kan nigbati a nkọ́ ọ lọwọ.
8 Ilẹkun yara ãrin mbẹ li apa ọtún ile
na: nwọn si fi àtẹgun ti o lọ́ri goke sinu
yàra ãrin, ati lati yara ãrin bọ sinu ẹkẹta.
9 Bẹ̃li o kọ́ ile na, ti o si pari rẹ̀: o si fi
gbelerù ati apako kedari bò ile na.
10 O si kọ́ yara gbè gbogbo ile na, igbọn-
wọ marun ni giga: o fi ìti kedari mú
wọn fi ara ti ile na.
11 Ọ̀rọ Oluwa si tọ Solomoni wá wipe,
12 Nipa ti ile yi ti iwọ nkọ́ lọwọ ni, bi
iwọ o ba rin ninu aṣẹ mi, ti iwọ o si ṣe
idajọ mi, ati ti iwọ o si pa gbogbo ofin mi
mọ lati ma rin ninu wọn, nigbana ni emi
o mu ọ̀rọ mi ṣẹ pẹlu rẹ, ti mo ti sọ fun
Dafidi, baba rẹ;
13 Emi o si ma gbe ãrin awọn ọmọ
Israeli, emi kì o si kọ̀ Israeli, enia mi.
14 Solomoni si kọ́ ile na, o si pari rẹ̀.
15 O si fi apako kedari tẹ́ ogiri ile na
ninu, lati ilẹ ile na de àja rẹ̀; o fi igi bò
wọn ninu, o si fi apako firi tẹ́ ilẹ ile na.
16 O si kọ́ ogún igbọnwọ ni ikangun ile
na, lati ilẹ de àja ile na li o fi apako kedari
kọ́, o tilẹ kọ́ eyi fun u ninu, fun ibi-ida-
hùn, ani ibimimọ́-julọ.
17 Ati ile na, eyini ni Tempili niwaju
rẹ̀, jẹ ogoji igbọnwọ ni gigùn.
18 Ati kedari ile na ninu ile li a fi irudi
ati itanna ṣe iṣẹ ọnà rẹ̀: gbogbo rẹ̀ kiki igi
kedari; a kò ri okuta kan.
19 Ibi-mimọ́-julọ na li o mura silẹ ninu
ile lati gbe apoti majẹmu Oluwa kà ibẹ.
20 Ibi-mimọ́-julọ na si jasi ogún igbọn-
wọ ni gigùn, li apa ti iwaju, ati ogún
igbọnwọ ni ibú, ati ogún igbọnwọ ni giga
rẹ̀; o si fi wura ailadàlu bò o, bẹ̃li o si fi
igi kedari bò pẹpẹ.
21 Solomoni si fi wura ailadàlu bò ile na
ninu: o si fi ẹwọ̀n wura ṣe oju ibi-mimọ́-
julọ, o si fi wura bò o.
22 Gbogbo ile na li o si fi wura bò titi o
fi pari gbogbo ile na; ati gbogbo pẹpẹ ti o
wà niha ibi-mimọ́-julọ li o fi wura bò.
23 Ati ninu ibi-mimọ́-julọ li o fi igi olifi
ṣe kerubu meji, ọkọkan jẹ igbọnwọ mẹwa
ni giga.
24 Ati igbọnwọ marun ni apa kerubu
kan, ati igbọnwọ marun ni apa kerubu
keji; lati igun apakan titi de igun apa-keji
jẹ igbọnwọ mẹwa.
25 Igbọnwọ mẹwa si ni kerubu keji:
kerubu mejeji jẹ ìwọn kanna ati titobi
kanna.
26 Giga kerubu kan jẹ igbọnwọ mẹwa,
bẹ̃ni ti kerubu keji.
27 O si fi awọn kerubu sinu ile ti inu
lọhun, nwọn si nà iyẹ-apa kerubu na, tobẹ̃

Digitized by Google

ti iyẹ-apa ọkan si kàn ogiri kan, ati iyẹ-apa kerubu keji si kàn ogiri keji: iyẹ-apa wọn si kàn ara wọn larin ile na.

28 O si fi wura bò awọn kerubu na.

29 O si yá aworan awọn kerubu lara gbogbo ogiri ile na yikakiri ati ti igi-ọpẹ, ati ti itanna eweko, ninu ati lode.

30 Ilẹ ile na li o fi wura tẹ́ ninu ati lode.

31 Ati fun oju-ọ̀na ibi-mimọ́-julọ li o ṣe ilẹkùn igi olifi: itẹrigbà ati opó ihà jẹ idamarun ogiri.

32 Ilẹkùn mejeji na li o si fi igi olifi ṣe; o si yá aworan awọn kerubu ati ti igi-ọpẹ, ati ti itanna eweko sara wọn, o si fi wura bò wọn, o si nà wura si ara awọn kerubu, ati si ara igi-ọpẹ.

33 Bẽli o si ṣe opó igi olifi olorigun mẹrin fun ilẹkun tempili na.

34 Ilẹkun mejeji si jẹ ti igi firi: awẹ́ meji ilẹkun kan jẹ iṣẹ́po, ati awẹ́ meji ilẹkun keji si jẹ iṣẹ́po.

35 O si yá awọn kerubu, ati igi-ọpẹ, ati itanna eweko si ara wọn: o si fi wura bò o, eyi ti o tẹ́ sori ibi ti o gbẹ́.

36 O si fi ẹsẹsẹ mẹta okuta gbigbẹ́, ati ẹsẹ kan ìti kedari kọ́ agbala ti inu ọhun.

37 Li ọdun kẹrin li a fi ipilẹ ile Oluwa le ilẹ̀, li oṣu Sifi.

38 Ati li ọdun kọkanla, li oṣu Bulu, ti iṣe oṣu kẹjọ, ni ile na pari jalẹ-jalẹ, pẹlu gbogbo ipin rẹ̀, gẹgẹ bi gbogbo eyi ti o yẹ: o si fi ọdun meje kọ́ ọ.

## ORI 7.

SUGBỌN Solomoni fi ọdun mẹtala kọ́ ile on tikararẹ̀, o si pari gbogbo iṣẹ ile rẹ̀.

2 O kọ́ ile-igbó Lebanoni pẹlu; gigùn rẹ̀ jasi ọgọrun igbọnwọ, ati ibú rẹ̀ adọta igbọnwọ, ati giga rẹ̀ ọgbọ̀n igbọnwọ, lori ọ̀wọ́ mẹrin opó igi kedari, ati idabu igi kedari lori awọn opó na.

3 A si fi igi kedari tẹ́ ẹ loke lori iyara ti o joko lori ọwọ̀n marunlelogoji, mẹdogun ni ọ̀wọ́.

4 Ferese si wà ni ọ̀wọ́ mẹta, oju si ko oju ni ọ̀na mẹta.

5 Gbogbo ilẹkun ati opó si dọgba ni igun mẹrin; oju si ko oju ni ọ̀na mẹta.

6 O si fi ọwọ̀n ṣe iloro: gigùn rẹ̀ jẹ adọta igbọnwọ, ibú rẹ̀ si jẹ ọgbọ̀n igbọnwọ, iloro kan si wà niwaju rẹ̀: ani ọwọ̀n miran, igi itẹsẹ ti o nipọn si mbẹ niwaju wọn.

7 O si ṣe iloro itẹ nibiti yio ma ṣe idajọ, ani iloro idajọ: a si fi igi kedari tẹ ẹ lati iha kan de keji.

8 Ile rẹ̀ nibiti o ngbe, ni agbala lẹhin ile titi de ọ̀dẹdẹ, si jẹ iṣẹ kanna. Solomoni si kọ́ ilẹ fun ọmọbirin Farao, ti o ni li aya, bi iloro yi.

9 Gbogbo wọnyi jẹ okuta iyebiye gẹgẹ bi iwọn okuta gbigbẹ́, ti a fi ayùn rẹ́ ninu ati lode, ani lati ipilẹ de ibori-oke ile, bẽ si ni lode si apa agbala nla.

10 Ipilẹ na jẹ okuta iyebiye, ani okuta nlanla, okuta igbọnwọ mẹwa, ati okuta igbọnwọ mẹjọ.

11 Ati okuta iyebiye wà loke nipa iwọ̀n okuta ti a gbẹ́, ati igi kedari.

12 Ati agbàla nla yikakiri pẹlu jẹ ọ̀wọ́ mẹta okuta gbigbẹ́, ati ọ̀wọ́ kan igi idabu ti kedari, ati fun agbala ile Oluwa ti inu lọhun, ati fun iloro ile na.

13 Solomoni ọba si ranṣẹ, o si mu Hiramu lati Tire wá.

14 Ọmọkọnrin opó kan ni, lati inu ẹya Naftali, baba rẹ̀ si ṣe ara Tire, alagbẹdẹ idẹ: on si kún fun ọgbọ́n, ati oye, ati ìmọ lati ṣe iṣẹkiṣẹ ni idẹ. O si tọ̀ Solomoni ọba wá, o si ṣe gbogbo iṣẹ rẹ̀.

15 O si dà ọwọ̀n idẹ meji, igbọnwọ mejidilogun ni giga ọkọkan: okùn igbọnwọ mejila li o si yi ọkọkan wọn ka.

16 O si ṣe ipari meji ti idẹ didà lati fi soke awọn ọwọ̀n na: giga ipari kan jẹ igbọnwọ marun, ati giga ipari keji jẹ igbọnwọ marun:

17 Ati oniruru iṣẹ, ati ohun wiwun iṣẹ ẹ̀wọn fun awọn ipari ti mbẹ lori awọn ọwọ̀n na; meje fun ipari kan, ati meje fun ipari keji.

18 O si ṣe awọn pomegranate ani ọ̀wọ́ meji yikakiri lara iṣẹ àwọn na, lati fi bò awọn ipari ti mbẹ loke: bẽli o si ṣe fun ipari keji.

19 Ati ipari ti mbẹ li oke awọn ọwọ̀n ti mbẹ ni ọ̀dẹdẹ na ti iṣẹ lili, ni igbọnwọ mẹrin.

20 Ati awọn ipari lori ọwọ̀n meji na wà loke: nwọn si sunmọ ibi ti o yọ lara ọwọ̀n ti o wà nibi iṣẹ àwọn: awọn pomegranate jẹ igba ni ọ̀wọ́ yikakiri, lori ipari keji.

21 O si gbe awọn ọwọ̀n na ro ni iloro tempili: o si gbe ọwọ̀n ọ̀tun ró, o si pe orukọ rẹ̀ ni Jakini: o si gbe ọwọ̀n òsi ró, o si pe orukọ rẹ̀ ni Boasi.

22 Lori oke awọn ọwọ̀n na ni iṣẹ lili wà; bẽni iṣẹ ti awọn ọwọ̀n si pari.

23 O si ṣe agbada nla didà igbọnwọ mẹwa lati eti kan de ekeji: o ṣe birikiti, giga rẹ̀ si jẹ igbọnwọ marun: okùn ọgbọ̀n igbọnwọ li o si yi i kakiri.

Digitized by Google

24 Ati nisalẹ eti rẹ̀ yikakiri kóko wà yi
i ka, mẹwa ninu igbọnwọ kan, o yi agbada
nla na kakiri: a dà kóko na ni ẹsẹ meji,
nigbati a dà a.
25 O duro lori malu mejila, mẹta nwo
iha ariwa, mẹta si nwo iwọ-õrun, mẽta si
nwo gusu, mẹta si nwo ila-õrun; agbada
nla na si joko lori wọn, gbogbo apa ẹhin
wọn si mbẹ ninu.
26 O si nipọn to ibú atẹlẹwọ, a si fi
itanna lili ṣiṣẹ eti rẹ̀ gẹgẹ bi eti ago, o si
gbà ẹgbã iwọ̀n Bati.
27 O si ṣe ijoko idẹ mẹwa; igbọnwọ
mẹrin ni gigùn ijoko kọkan, igbọnwọ mẹ-
rin si ni ibú rẹ̀, ati igbọnwọ mẹta ni giga
rẹ̀.
28 Iṣẹ awọn ijoko na ri bayi: nwọn ni
alafo ọ̀na arin, alafo ọ̀na arin na si wà
lagbedemeji ipade eti.
29 Ati lara alafo ọ̀na arin ti mbẹ lagbe-
demeji ni aworan kiniun, malu, ati awọn
kerubu wà; ati lori ipade eti, ijoko kan
wà loke: ati labẹ awọn kiniun, ati malu
ni iṣẹ ọṣọ́ wà.
30 Olukuluku ijoko li o ni ayika kẹkẹ́
idẹ mẹrin, ati ọpa kẹkẹ́ idẹ: igun mẹrẹrin
rẹ̀ li o ni ifẹsẹtẹ labẹ; labẹ agbada na
ni ifẹsẹtẹ didà wà, ni iha gbogbo iṣẹ ọṣọ́
na.
31 Ẹnu rẹ̀ ninu ipari na ati loke jẹ igbọn-
wọ kan: ṣugbọn ẹnu rẹ̀ yika gẹgẹ bi iṣẹ
ijoko na, si jẹ igbọnwọ kan on àbọ: ati li
ẹnu rẹ̀ ni ohun ọnà gbigbẹ́ wà pẹlu alafo
ọ̀na arin wọn, nwọn si dọgba ni igun mẹrẹ-
rin, nwọn kò yika.
32 Ati nisalẹ alafo ọ̀na arin, ayika-kẹkẹ́
mẹrin li o wà: a si so ọpa ayika-kẹkẹ́ na
mọ ijoko na; giga ayika-kẹkẹ́ kan si jẹ
igbọnwọ kan pẹlu àbọ.
33 Iṣẹ ayika-kẹkẹ́ na si dabi iṣẹ kẹkẹ́;
ri idalu wọn, ati ibi iho, ati ibi ipade, ati
bukala wọn, didà ni gbogbo wọn.
34 Ifẹsẹtẹ mẹrin li o wà fun igun mẹrin
ijoko na: ifẹsẹtẹ na si jẹ ti ijoko tikararẹ̀
apã.
35 Ati loke ijoko na, ayika kan wà ti
ọ igbọnwọ: ati loke ijoko na ẹgbẹgbẹti
ati alafo ọ̀na arin rẹ̀ jẹ bakanna.
36 Ati lara iha ẹgbẹti rẹ̀, ati leti rẹ̀,
o gbẹ́ aworan kerubu, kiniun, ati igi-
ọ gẹgẹ bi aye olukuluku, ati iṣẹ ọṣọ
kakiri.
37 Gẹgẹ bayi li o si ṣe awọn ijoko mẹ-
wa: gbogbo wọn li o si ni didà kanna,
ọ̀n kanna, ati titobi kanna.
38 O si ṣe agbada idẹ mẹwa: agbada
kan gbà to ọ̀ji iwọn Bati: agbada kọ̃kan
si jẹ igbọnwọ mẹrin: lori ọkọ̃kan ijoko
mẹwẹwa na ni agbada kọ̃kan wà.
39 O si fi ijoko marun si apa ọtún ile na,
ati marun si apa òsi ile na: o si gbe agba-
da-nla ka apa ọtún ile na, si apa ila-õrun si
idojukọ gusu:
40 Hiramu si ṣe ikoko ati ọkọ́, ati awọ-
koto. Bẽni Hiramu si pari gbogbo iṣẹ ti o
ṣe fun ile Oluwa fun Solomoni ọba:
41 Ọwọ̀n meji, ati ọpọn meji ipari ti
mbẹ loke awọn ọwọ̀n meji; ati iṣẹ àwọ̀n
meji lati bò ọpọ́n meji ipari ti mbẹ loke
awọn ọwọ̀n;
42 Ati irinwo pomegranate fun iṣẹ àwọ̀n
meji, ọ̀wọ́ meji pomegranate fun iṣẹ àwọ̀n
kan, lati bò awọn ọpọ́n meji ipari ti mbẹ
loke awọn ọwọ̀n;
43 Ati ijoko mẹwa, ati agbada mẹwa
lori awọn ijoko na.
44 Agbada nla kan, ati malu mejila labẹ
agbada nla.
45 Ati ikoko, ati ọkọ́, ati awo-koto;
ati gbogbo ohun-elo wọnyi ti Hiramu ṣe
fun ile Oluwa fun Solomoni ọba, jẹ ti idẹ
didan.
46 Ni pẹtẹlẹ Jordani ni ọba dà wọn, ni
ilẹ amọ̀ ti mbẹ lagbedemeji Sukkoti on
Sartani.
47 Solomoni si jọwọ gbogbo ohun-elo na
silẹ li alaiwọ̀n, nitori ti nwọn papọju:
bẽni a kò si mọ̀ iwọ̀n idẹ na.
48 Solomoni si ṣe gbogbo ohun-ẹlo ti
iṣe ti ile Oluwa: pẹpẹ wura, ati tabili
wura, lori eyi ti akara ifihan gbe wà.
49 Ati ọpa fitila wura daradara, marun
li apa ọtún ati marun li apa òsi, niwaju
ibi mimọ́-julọ, pẹlu itanna eweko, ati
fitila, ati ẹ̀mú wura.
50 Ati ọpọ́n, ati alumagaji-fitila, ati
awo-koto, ati ṣibi, ati awo turari ti wura
daradara; ati agbekọ wura, fun ilẹkun
inu ile, ibi mimọ́-julọ, ati fun ilẹkun ile
na, ani ti tempili.
51 Bẽni gbogbo iṣẹ ti Solomoni ọba ṣe
fun ile Oluwa pari. Solomoni si mu
gbogbo nkan ti Dafidi baba rẹ̀ ti yà si
mimọ́ wá; fadaka, ati wura, ati ohun-elo,
o si fi wọn sinu iṣura ile Oluwa.

## ORI 8.

NIGBANA ni Solomoni papejọ awọn
agba Israeli, ati gbogbo awọn olori
awọn ẹya, awọn olori awọn baba awọn
ọmọ Israeli, si ọdọ Solomoni ọba ni Jeru-
salemu, ki nwọn ki o lè gbe apoti-ẹri

Digitized by Google

majẹmu Oluwa wá lati ilu Dafidi, ti iṣe
Sioni.
2 Gbogbo awọn ọkọnrin Israeli si pe
ara wọn jọ si ọdọ Solomoni ọba ni ajọ
ọdun ni oṣu Etanimu, ti iṣe oṣu keje.
3 Gbogbo awọn agbàgba Israeli si wá,
awọn alufa si gbe apoti-ẹri.
4 Nwọn si gbe apoti-ẹ̀ri Oluwa wá soke,
ati agọ ajọ enia, ati gbogbo ohun-elo mimọ́
ti o wà ninu agọ, ani nkan wọnni ni awọn
alufa ati awọn ọmọ Lefi gbe goke wá.
5 Ati Solomoni ọba, ati gbogbo ijọ enia
Israeli ti o pejọ si ọdọ rẹ̀ wà pẹlu rẹ̀ niwaju
apoti-ẹri, nwọn nfi agutan ati malu ti a
kò le mọ̀ iye, ti a kò le kà fun ọ̀pọlọpọ
rubọ.
6 Awọn afufa si gbe apoti-ẹri majẹmu
Oluwa wá si ipò rẹ̀ sinu ibi-idahùn ile
na, ni ibi mimọ́-julọ labẹ iyẹ awọn kerubu.
7 Nitori awọn kerubu nà iyẹ wọn me-
jeji si ibi apoti-ẹri, awọn kerubu na si bò
apọti-ẹri ati awọn ọpá rẹ̀ lati oke wá.
8 Nwọn si fa awọn ọpá na jade tobẽ ti
a nfi ri ori awọn ọpá na lati ibi mimọ́
niwaju ibi-idahùn, a kò si ri wọn lode:
nibẹ ni nwọn si wà titi di oni yi.
9 Kò si nkankan ninu apoti-ẹri bikoṣe
tabili okuta meji, ti Mose ti fi si ibẹ ni
Horebu nigbati Oluwa ba awọn ọmọ Isra-
eli dá majẹmu, nigbati nwọn ti ilẹ Egipti
jade.
10 O si ṣe, nigbati awọn alufa jade lati
ibi mimọ́ wá, awọsanma si kún ile Oluwa.
11 Awọn alufa kò si le duro ṣiṣẹ nitori
awọsanma na: nitori ogo Oluwa kún ile
Oluwa.
12 Nigbana ni Solomoni sọ pe: Oluwa
ti wi pe, on o mã gbe inu okùnkun biri-
biri.
13 Nitõtọ emi ti kọ́ ile kan fun ọ lati
mã gbe inu rẹ̀, ibukojo kan fun ọ lati mã
gbe inu rẹ̀ titi lai.
14 Ọba si yi oju rẹ̀, o si fi ibukún fun
gbogbo ijọ enia Israeli: gbogbo ijọ enia
Israeli si dide duro;
15 O si wipe, Ibukún ni fun Oluwa,
Ọlọrun Israeli, ti o fi ẹnu rẹ̀ sọ̀rọ fun
Dafidi, baba mi, ti o si fi ọwọ́ rẹ̀ mu u ṣẹ,
wipe,
16 Lati ọjọ ti emi ti mu Israeli, awọn
enia mi jade kuro ni Egipti, emi kò yàn
ilu kan ninu gbogbo ẹyà Israeli lati kọ́
ile kan, ki orukọ mi ki o le mã gbe inu
rẹ̀: ṣugbọn emi yàn Dafidi ṣe olori Israeli,
awọn enia mi.
17 O si wà li ọkàn Dafidi, baba mi,
lati kọ́ ile kan fun orukọ Oluwa, Ọlọrun
Israeli.
18 Oluwa si wi fun Dafidi baba mi pe,
Bi o tijẹpe o wà li ọkàn rẹ lati kọ́ ile kan
fun orukọ mi, iwọ ṣe rere ti o fi wà li
ọkàn rẹ.
19 Sibẹ̀ iwọ kì yio kọ́ ile na, ṣugbọn
ọmọ rẹ ti yio ti inu rẹ jade, on ni yio kọ́
ile na fun orukọ mi.
20 Oluwa si mu ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ ti o ti sọ,
emi si dide ni ipò Dafidi, baba mi, mo
si joko lori itẹ́ Israeli, gẹgẹ bi Oluwa ti
sọ, emi si kọ́ ile kan fun orukọ Oluwa,
Ọlọrun Israeli.
21 Emi si ti ṣe àye kan nibẹ̀ fun apoti-
ẹri, ninu eyiti majẹmu Oluwa gbe wà, ti
o ti ba awọn baba wa dá, nigbati o mu
wọn jade lati ilẹ Egipti wá.
22 Solomoni si duro niwaju pẹpẹ Oluwa,
loju gbogbo ijọ enia Israeli, o si nà ọwọ́
rẹ̀ mejeji soke ọrun:
23 O si wipe, Oluwa Ọlọrun Israeli, kò
si Ọlọrun ti o dabi rẹ loke ọrun, tabi ni
isalẹ ilẹ, ti ipa majẹmu ati ãnu mọ pẹlu
awọn iranṣẹ rẹ ti nfi gbogbo ọkàn wọn
rin niwaju rẹ:
24 Ẹniti o ti ba iranṣẹ rẹ Dafidi, baba
mi pa ohun ti iwọ ti ṣe ileri fun u mọ:
iwọ fi ẹnu rẹ sọ pẹlu, o si ti fi ọwọ́ rẹ mu
u ṣẹ, gẹgẹ bi o ti ri loni.
25 Njẹ nisisiyi, Oluwa Ọlọrun Israeli,
ba iranṣẹ rẹ Dafidi, baba mi pa ohun ti
iwọ ti ṣe ileri fun u mọ́ wipe, A kì yio
fẹ ọkọnrin kan kù li oju mi lati joko
lori itẹ Israeli; kiki bi awọn ọmọ rẹ ba
le kiyesi ọ̀na wọn, ki nwọn ki o mã rìn
niwaju mi gẹgẹ bi iwọ ti rìn niwaju mi.
26 Njẹ nisisiyi, Ọlọrun Israeli, jẹ ki a
mu ọ̀rọ rẹ ṣẹ, emi bẹ̀ ọ, ti iwọ ti sọ fun
iranṣẹ rẹ, Dafidi baba mi.
27 Ṣugbọn nitõtọ Ọlọrun yio ha mã gbe
aiye bi? wò o, ọrun ati ọrun awọn ọrun
kò le gbà ọ; ambọ̀sì ile yi ti mo kọ́?
28 Sibẹ̀ iwọ ṣe afiyèsi adura iranṣẹ rẹ,
ati si ẹbẹ rẹ̀, Oluwa Ọlọrun mi, lati tẹtisilẹ
si ẹkun ati si adura, ti iranṣẹ rẹ ngbà
niwaju rẹ loni:
29 Ki oju rẹ lè ṣi si ile yi li ọsan ati
li oru, ani si ibi ti iwọ ti wipe: Orukọ mi
yio wà nibẹ: ki iwọ ki o lè tẹtisilẹ si
adura ti iranṣẹ rẹ yio gbà si ibi yi.
30 Ki o si tẹtisilẹ si ẹ̀bẹ iranṣẹ rẹ ati
ti Israeli, enia rẹ, ti nwọn o gbadura siha
ibi yi: ki o si gbọ́ li ọrun, ibugbe rẹ! gbọ́,
ki o si dariji.
31 Bi ẹnikan ba ṣẹ̀ si ẹnikeji rẹ̀, ti a

Digitized by Google

si fi ibura le e lati mu u bura, bi ibura na ba si de iwaju pẹpẹ rẹ ni ile yi:

32 Nigbana ni ki o gbọ́ li ọrun, ki o si ṣe, ki o si dajọ awọn iranṣẹ rẹ, ni didẹbi fun enia buburu, lati mu ọ̀na rẹ̀ wá si ori rẹ̀; ati ni didare fun olõtọ, lati fun u gẹgẹ bi ododo rẹ̀.

33 Nigbati a ba lù Israeli, enia rẹ bọ̀lẹ niwaju awọn ọ̀ta, nitoriti nwọn dẹṣẹ si ọ, ti nwọn ba si yipada si ọ, ti nwọn si jẹwọ orukọ rẹ, ti nwọn si gbadura, ti nwọn si bẹ̀bẹ lọdọ rẹ ni ile yi:

34 Nigbana ni ki o gbọ́ li ọrun, ki o si dari ẹ̀ṣẹ Israeli, enia rẹ jì, ki o si mu wọn pada wá si ilẹ ti iwọ ti fi fun awọn baba wọn.

35 Nigbati a ba sé ọrun mọ, ti kò si òjo, nitoriti nwọn ti dẹṣẹ si ọ: bi nwọn ba gbadura si iha ibi yi, ti nwọn si jẹwọ orukọ rẹ, bi nwọn ba si yipada kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn, nigbati iwọ ba pọ́n wọn li oju.

36 Nigbana ni ki o gbọ́ li ọrun, ki o si dari ẹ̀ṣẹ awọn iranṣẹ rẹ jì, ati ti Israeli, enia rẹ, nigbati o kọ́ wọn li ọ̀na rere ninu eyiti nwọn iba mã rin, ki o si rọ̀ òjo si ilẹ rẹ, ti iwọ ti fi fun enia rẹ ni ilẹ-ini.

37 Bi iyàn ba mu ni ilẹ, bi ajakalẹ-arùn ni, tabi irẹdanu, tabi bibu, tabi bi ẽsu tabi bi kòkorò ti njẹrun ba wà; bi ọtá wọn ba dó tì wọn ni ilẹ ilu wọn; ajakalẹ-arùn gbogbo, arùn-ki-arun gbogbo.

38 Adura ki adura, ati ẹ̀bẹ ki ẹ̀bẹ, ti a ba ti ọdọ ẹnikan lati ọdọ gbogbo Israeli, enia rẹ gbà, ti olukuluku yio mọ̀ ibanujẹ ọkàn ara rẹ̀, bi o ba si tẹ́ ọwọ́ rẹ̀ mejeji si iha ile yi!

39 Nigbana ni ki iwọ ki o gbọ́ li ọrun, ibugbe rẹ, ki o si darijì, ki o si ṣe ki o si fun olukulùku enia gẹgẹ bi ọ̀na rẹ̀, ọkàn ẹniti iwọ mọ̀; nitoriti iwọ, iwọ nikanṣoṣo li o mọ́ ọkàn gbogbo awọn ọmọ enia;

40 Ki nwọn ki o lè mã bẹ̀ru rẹ ni gbogbo ọjọ ti nwọn wà ni ilẹ ti iwọ fi fun awọn baba wa.

41 Pẹlupẹlu, niti alejò, ti kì iṣe ti inu Israeli enia rẹ, ṣugbọn ti o ti ilẹ okerè jade wá nitori orukọ rẹ.

42 Nitoriti nwọn o gbọ́ orukọ nla rẹ, ati ọwọ́ agbàra rẹ, ati ninà apa rẹ; nigbati on o wá, ti yio si gbadura si iha ile yi;

43 Iwọ gbọ́ li ọrun, ibùgbe rẹ, ki o si ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti alejò na yio ke pè ọ si: ki gbogbo aiye ki o lè mọ̀ orukọ rẹ, ki nwọn ki o lè mã bẹ̀ru rẹ, gẹgẹ bi Israeli, enia rẹ, ki nwọn ki o si lè mọ̀ pe: orukọ rẹ li a fi npè ile yi ti mo kọ́.

44 Bi enia rẹ ba jadẹ lọ si ogun si ọtá wọn, li ọ̀na ti iwọ o rán wọn, bi nwọn ba si gbadura si Oluwa siha ilu ti iwọ ti yàn, ati siha ile ti mo kọ́ fun orukọ rẹ.

45 Nigbana ni ki o gbọ́ adura wọn, ati ẹ̀bẹ wọn li ọrun, ki o si mu ọràn wọn duro.

46 Bi nwọn ba ṣẹ̀ si ọ, nitoriti kò si enia kan ti kì iṣẹ̀, bi iwọ ba si binu si wọn, ti o si fi wọn le ọwọ́ ọta, tobẽ ti a si kó wọn lọ ni igbèkun si ilẹ ọta, jijìna tabi nitosi;

47 Bi nwọn ba rò inu ara wọn wò ni ilẹ nibiti a gbe kó wọn ni igbèkun lọ, ti nwọn ba si ronupiwàda, ti nwọn ba si bẹ̀ ọ ni ilẹ awọn ti o kó wọn ni igbèkun lọ, wipe, Awa ti dẹṣẹ, awa ti ṣe ohun ti kò tọ, awa ti ṣe buburu;

48 Bi nwọn ba si fi gbogbo àiya ati gbogbo ọkàn wọn yipada si ọ ni ilẹ awọn ọta wọn, ti o kó wọn ni igbèkun lọ, ti nwọn si gbadura si ọ siha ilẹ wọn, ti iwọ ti fi fun awọn baba wọn, ilu ti iwọ ti yàn, ati ile ti emi kọ́ fun orukọ rẹ:

49 Nigbana ni ki iwọ ki o gbọ́ adura wọn ati ẹ̀bẹ wọn li ọrun ibugbe rẹ, ki o si mu ọ̀ran wọn duro:

50 Ki o si darijì awọn enia rẹ ti o ti dẹṣẹ si ọ, ati gbogbo irekọja wọn ninu eyiti nwọn ṣẹ̀ si ọ, ki o si fun wọn ni ãnu niwaju awọn ti o kó wọn ni igbèkun lọ, ki nwọn ki o le ṣãnu fun wọn.

51 Nitori enia rẹ ati ini rẹ ni nwọn, ti iwọ mu ti Egipti jade wá, lati inu ileru irin:

52 Ki oju rẹ ki o le ṣi si ẹ̀bẹ iranṣẹ rẹ, ati si ẹ̀bẹ Israeli enia rẹ, lati tẹtisilẹ si wọn ninu ohun gbogbo ti nwọn o ke pè ọ si.

53 Nitoriti iwọ ti yà wọn kuro ninu gbogbo orilẹ-ède aiye, lati mã jẹ ini rẹ, bi iwọ ti sọ lati ọwọ Mose iranṣẹ rẹ, nigbati iwọ mu awọn baba wa ti Egipti jade wá, Oluwa Ọlọrun.

54 O si ṣe, bi Solomoni ti para gbigbà gbogbo adura ati ẹ̀bẹ yi si Oluwa, o dide kuro lori ikunlẹ ni ẽkún rẹ̀ niwaju pẹpẹ Oluwa, pẹlu titẹ́ ọwọ rẹ̀ si oke ọrun.

55 O si dide duro, o si fi ohùn rara sure fun gbogbo ijọ enia Israeli wipe,

56 Ibukún ni fun Oluwa ti o ti fi isimi fun Israeli enia rẹ̀, gẹgẹ bi gbogbo eyiti o ti ṣe ileri: kò kù ọ̀rọ kan ninu gbogbo ileri rere rẹ̀ ti o ti ṣe lati ọwọ Mose, iranṣẹ rẹ̀ wá.

57 Oluwa Ọlọrun wa ki o wà pẹlu wa, bi o ti wà pẹlu awọn baba wa: ki o má fi wa silẹ, ki o má si ṣe kọ̀ wa silẹ;

58 Ṣugbọn ki o fa ọkàn wa si ọdọ ara

Digitized by Google

rẹ̀, lati ma rin ninu gbogbo ọ̀na rẹ̀, ati lati pa ofin rẹ̀ mọ́, ati aṣẹ rẹ̀, ati idajọ rẹ̀, ti o ti paṣẹ fun awọn baba wa.

59 Ki o si jẹ ki ọ̀rọ mi wọnyi, ti mo fi bẹ̀bẹ niwaju Oluwa, ki o wà nitosi, Oluwa Ọlọrun wa, li ọsan ati li oru, ki o le mu ọ̀ran iranṣẹ rẹ duro, ati ọ̀ran ojojumọ ti Israeli, enia rẹ̀.

60 Ki gbogbo enia aiye le mọ̀ pe, Oluwa on li Ọlọrun, kò si ẹlomiran.

61 Nitorina, ẹ jẹ ki aiya nyin ki o pé pẹlu Oluwa Ọlọrun wa, lati mã rìn ninu aṣẹ rẹ̀, ati lati pa ofin rẹ̀ mọ́, bi ti oni yi.

62 Ati ọba, ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀, ru ẹbọ niwaju Oluwa.

63 Solomoni si ru ẹbọ ọrẹ-alafia, ti o ru si Oluwa, ẹgbã-mọkanla malu, ati ọkẹ mẹfa àgutan. Bẹ̃ni ọba ati gbogbo awọn ọmọ Israeli yà ilẹ Oluwa si mimọ́.

64 Li ọ̀jọ na ni ọba yà agbàla ãrin ti mbẹ niwaju ile Oluwa si mimọ́: nitori nibẹ ni o ru ẹbọ ọrẹ-sisun, ati ọrẹ-onje, ati ẹbọ-ọpẹ: nitori pẹpẹ idẹ ti mbẹ niwaju Oluwa kere jù lati gba ọrẹ-sisun ati ọrẹ-ọnjẹ, ati ọ̀ra ẹbọ-ọpẹ.

65 Ati li àkoko na, Solomoni papejọ kan, ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀, ajọ nla-nlã ni, lati iwọ Hamati titi de odò Egipti, niwaju Oluwa Ọlọrun wa, ijọ meje on ijọ meje, ani ijọ mẹrinla.

66 Li ọjọ kẹjọ o rán awọn enia na lọ: nwọn si sure fun ọba, nwọn si lọ sinu agọ wọn pẹlu ayọ̀ ati inu-didun, nitori gbogbo ore ti Oluwa ti ṣe fun Dafidi, iranṣẹ rẹ̀, ati fun Israeli, enia rẹ̀.

## ORI 9.

O SI ṣe, bi Solomoni ti pari kikọ́ ilẹ Oluwa, ati ile ọba, ati gbogbo ifẹ Solomoni ti o wù u lati ṣe,

2 Oluwa fi ara hàn Solomoni li ẹrinkeji, gẹgẹ bi o ti fi ara hàn a ni Gibeoni.

3 Oluwa si wi fun u pe, Mo ti gbọ́ adura rẹ ati ẹ̀bẹ rẹ, ti iwọ ti bẹ̀ niwaju mi, mo ti ya ile yi si mimọ́, ti iwọ ti kọ́, lati fi orukọ mi sibẹ titi lai; ati oju mi ati ọkàn mi yio wà nibẹ titi lai.

4 Bi iwọ o ba rìn niwaju mi: bi Dafidi baba rẹ ti rìn, ni otitọ ọkàn, ati ni iduroṣinṣin, lati ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti mo ti pa li aṣẹ fun ọ, ti iwọ o si pa aṣẹ mi ati idajọ mi mọ́:

5 Nigbana li emi o fi idi itẹ́ ijọba rẹ mulẹ lori Israeli titi lai, bi mo ti ṣe ileri fun Dafidi baba rẹ, wipe, Iwọ kì yio fẹ ọkọnrin kan kù lori itẹ́ Israeli.

6 Ṣugbọn bi ẹnyin o ba yipada lati má tọ̀ mi lẹhin, ẹnyin, tabi awọn ọmọ nyin, bi ẹnyin kò si pa ofin mi mọ́, ati aṣẹ mi ti mo ti fi si iwaju nyin, ṣugbọn bi ẹ ba lọ ti ẹ si sìn awọn ọlọrun miran, ti ẹ si bọ wọn:

7 Nigbana ni emi o ké Israeli kuro ni ilẹ ti emi fi fun wọn; ati ile yi, ti mo ti yà si mimọ́ fun orukọ mi li emi o gbe sọnù kuro niwaju mi; Israeli yio si di owe ati ifiṣẹsin lãrin gbogbo orilẹ-ède.

8 Ati ile yi, ti o ga, ẹnu o si ya olukuluku ẹniti o kọja lẹba rẹ̀, yio si pòṣe: nwọn o si wipe; ẽṣe ti Oluwa fi ṣe bayi si ilẹ yi ati si ile yi?

9 Nwọn o si dahùn wipe, Nitoriti nwọn kọ̀ Oluwa Ọlọrun wọn silẹ, ẹniti o mu awọn baba wọn jade ti ilẹ Egipti wá, nwọn gbá awọn ọlọrun miran mú, nwọn si bọ wọn, nwọn si sìn wọn: nitorina ni Oluwa ṣe mu gbogbo ibi yi wá sori wọn.

10 O si ṣe lẹhin ogún ọdun, nigbati Solomoni ti kọ́ ile mejeji tan, ile Oluwa, ati ile ọba.

11 Hiramu, ọba Tire ti ba Solomoni wá igi kedari ati igi firi, ati wura gẹgẹ bi gbogbo ifẹ rẹ̀, nigbana ni Solomoni ọba fun Hiramu ni ogún ilu ni ilẹ Galili.

12 Hiramu si jade lati Tire wá lati wò ilu ti Solomoni fi fun u: nwọn kò si wù u.

13 On si wipe, Ilu kini wọnyi ti iwọ fi fun mi, arakọnrin mi? O si pè wọn ni ilẹ Kabulu titi fi di oni yi.

14 Hiramu si fi ọgọta talenti wura ranṣẹ si ọba.

15 Idi awọn asìnru ti Solomoni kojo ni eyi; lati kọ́ ile Oluwa, ati ile on tikararẹ̀, ati Millo, ati odi Jerusalemu, ati Hasori ati Megiddo, ati Geseri.

16 Farao, ọba Egipti ti goke lọ, o si ti kó Geseri, o si ti fi iná sun u, o si ti pa awọn ara Kenaani ti ngbe ilu na, o si fi ta ọmọbirin rẹ, aya Solomoni li ọrẹ.

17 Solomoni si kọ́ Geseri, ati Bethoroni isalẹ.

18 Ati Baalati, ati Tadmori ni aginju, ni ilẹ na.

19 Ati gbogbo ilu iṣura ti Solomoni ni, ati ilu kẹkẹ́ rẹ̀, ati ilu fun awọn ẹlẹsin rẹ̀, ati eyiti Solomoni nfẹ lati kọ́ ni Jerusalemu, ati ni Lebanoni, ati ni gbogbo ilẹ ijọba rẹ̀.

20 Gbogbo enia ti o kù ninu awọn ara Amori, ara Hitti, Perisi, Hifi ati Jebusi, ti kì iṣe ti inu awọn ọmọ Israeli.

21 Awọn ọmọ wọn ti o kù lẹhin wọn ni ilẹ na, ti awọn ọmọ Israeli kò le parun

Digitized by Google

tūtu, awọn ni Solomoni bù iṣẹ-iru fun titi
di oni yi.
22 Ṣugbọn ninu awọn ọmọ Israeli, Solo-
moni kò fi ṣe ẹrú, ṣugbọn nwọn jẹ awọn
ologun ati awọn iranṣẹ rẹ̀, ati awọn ijoye
rẹ̀, ati awọn balogun rẹ̀, ati awọn olori
kẹkẹ́ rẹ̀ ati ti awọn ẹlẹṣin rẹ̀.
23 Awọn wọnyi ni awọn olori olutọju ti
mbẹ lori iṣẹ Solomoni, ãdọta-dilẹgbẹta, ti
nṣe akoso lori awọn enia ti nṣe iṣẹ na.
24 Ṣugbọn ọmọbirin Farao goke lati ilu
Dafidi wá si ile rẹ̀, ti Solomoni kọ́ fun u:
nigbana ni o kọ́ Millo.
25 Ati nigba mẹta li ọdun ni Solomoni
iru ẹbọ ọrẹ-sisun, ati ẹbọ-ọpẹ lori pẹpẹ ti o
tẹ́ fun Oluwa, o si sun turari lori eyi ti
mbẹ niwaju Oluwa. Bẹ̃li o pari ile na.
26 Solomoni ọba si sẹ ọ̀wọ-ọkọ̀ ni Esioni-
Geberi, ti mbẹ li ẹba Eloti, leti Okun-pupa
ni ilẹ Edomu.
27 Hiramu si rán awọn iranṣẹ rẹ̀, awọn
atukọ ti o ni ìmọ okun, pẹlu awọn iranṣẹ
Solomoni ninu ọ̀wọ-ọkọ̀ na.
28 Nwọn si de Ofiri, nwọn si mu wura
lati ibẹ wá, irinwo talenti o le ogun, nwọn
si mu u fun Solomoni ọba wá.

## ORI 10.

NIGBATI ayaba Ṣeba si gbọ́ okiki Solo-
moni niti orukọ Oluwa, o wá lati fi
ilọ dán a wò.
2 O si wá si Jerusalemu pẹlu ẹgbẹ nla-
nla, ibakasiẹ ti o ru turari, ati ọ̀pọlọpọ
wura, ati okuta oniyebyie: nigbati o si de
ọdọ Solomoni o ba a sọ gbogbo eyiti mbẹ li
ọkàn rẹ̀.
3 Solomoni si fi èsi si gbogbo ọ̀rọ rẹ̀, kò
si ibère kan ti o pamọ fun ọba ti kò si
sọ fun u.
4 Nigbati ayaba Ṣeba si ti ri gbogbo
ọgbọ́n Solomoni, ati ile ti o ti kọ́.
5 Ati onjẹ tabili rẹ̀, ati ijoko awọn ọmọ-
ọdọ rẹ̀, ati iduro awọn iranṣẹ rẹ̀, ati iwọṣọ
wọn, ati awọn agbọti rẹ̀, ati ọna ti o mba
goke lọ si ile Oluwa; kò kù agbara kan
ninu u mọ.
6 O si wi fun ọba pe, Otitọ li ọ̀rọ ti mo
gbọ́ ni ilẹ mi niti iṣe rẹ ati niti ọgbọ́n rẹ.
7 Ṣugbọn emi kò gba ọ̀rọ na gbọ́, titi
mo fi de, ti oju mi si ti ri: si kiyesi i, a kò
sọ idajì wọn fun mi: iwọ si ti fi ọgbọ́n ati
ire kún okiki ti mo gbọ́.
8 Ibukún ni fun awọn enia rẹ, ibukún
ni fun awọn iranṣẹ rẹ wọnyi, ti nduro ni-
waju rẹ nigbagbogbo, ti ngbọ́ ọgbọ́n rẹ.
9 Alabukún fun li Oluwa Ọlọrun rẹ, ti
o ni inu-didùn si ọ lati gbe ọ ka ori itẹ́
Israeli: nitoriti Oluwa fẹràn Israeli titi
lai, nitorina li o ṣe fi ọ jọba, lati ṣe idajọ
ati otitọ.
10 On si fun ọba li ọgọfa talenti wura,
ati turari lọpọlọpọ ati okuta iyebiye: iru
ọ̀pọlọpọ turari bẹ̃ kò de mọ bi eyiti ayaba
Ṣeba fi fun Solomoni, ọba.
11 Pẹlupẹlu awọn ọ̀wọ-ọkọ̀ Hiramu ti o
mu wura lati Ofiri wá, mu igi Algumu,
(igi Sandali) lọpọlọpọ ati okuta oniyebiye
lati Ofiri wá.
12 Ọba si fi igi Algumu na ṣe opó fun
ile Oluwa, ati fun ile ọba, dùru pẹlu ati
ohun-elo orin miran fun awọn akọrin: iru
igi Algumu bẹ̃ kò de mọ, bẹ̃ni a kò ri wọn
titi di oni yi.
13 Solomoni ọba si fun ayaba Ṣeba ni
gbogbo ifẹ rẹ̀, ohunkohun ti o bère, li aika
eyiti a fi fun u lati ọwọ Solomoni ọba wá.
Bẹ̃li o si yipada, o si lọ si ilu rẹ̀, on, ati
awọn iranṣẹ rẹ̀.
14 Njẹ ìwọn wura ti o nde ọdọ Solo-
moni li ọdun kan, jẹ ọtalelẹgbẹta o le mẹfa
talenti wura,
15 Laika eyi ti o ngbà lọwọ awọn ajẹlẹ
ati awọn oniṣowo, ati ti gbogbo awọn ọba
Arabia, ati ti awọn bãlẹ ilẹ.
16 Solomoni ọba si ṣe igba asà wura
lilù: ẹgbẹta ṣekeli wura li o tán si asà
kan.
17 O si ṣe ọdunrun apata wura lilù, oṣu-
wọn wura mẹta li o tán si apata kan: ọba
si ko wọn si ile igbo Lebanoni.
18 Ọba si ṣe itẹ́ ehin-erin kan nla, o si fi
wura didara julọ bò o.
19 Itẹ́ na ni atẹgùn mẹfa, oke itẹ́ na yi
okiribiti lẹhin: irọpá si wà niha kini ati
ekeji ni ibi ijoko na, kiniun meji si duro
lẹba na
20 Kiniun mejila duro nibẹ niha ekini
ati ekeji lori atẹgùn mẹfa na: a kò ṣe iru
rẹ̀ ni ijọba kan.
21 Ati gbogbo ohun-elo mimu Solomoni
ọba jẹ wura, ati gbogbo ohun-elo ile igbo
Lebanoni jẹ wura daradara; kò si fadaka;
a kò kà a si nkankan li ọjọ Solomoni.
22 Nitori ọba ni ọkọ̀ Tarṣiṣi kan pẹlu
ọkọ̀ Hiramu li okun: ẽkan li ọdun mẹta li
ọkọ̀ Tarṣiṣi idé, ti imu wura ati fadaka,
ehin-erin ati inakí ati ẹiyẹ-ologe wá.
23 Solomoni ọba si pọ̀ jù gbogbo awọn
ọba aiye lọ, li ọrọ̀ ati li ọgbọ́n.
24 Gbogbo aiye si nwá oju Solomoni,
lati gbọ́ ọgbọ́n rẹ̀, ti Ọlọrun ti fi si i li
ọkàn.



Digitized by Google

25 Olukuluku nwọn si mu ọrẹ tirẹ̀ wá, ohun-elo fadaka, ati ohun-elo wura, ati ẹ̀wu, ati turari, ẹṣin ati ibãka, iye kan lọdọdun.
26 Solomoni si ko kẹkẹ́ ati ẹ̀ṣin jọ: o si ni egbeje kẹkẹ́ ati ẹgbãfa ẹlẹṣin, o si fi wọn si ilu kẹkẹ́, ati pẹlu ọba ni Jerusalemu.
27 Ọba si ṣe ki fadakà ki o wà ni Jerusalemu bi okuta, ati igi kedari li o ṣe ki o dabi igi sikamore ti mbẹ ni afonifoji fun ọ̀pọlọpọ.
28 A si mu ẹṣin wá fun Solomoni lati Egipti li ọwọ́wọ, oniṣowo ọba nmu wọn wá fun owo.
29 Kẹkẹ́ kan ngoke o si njade lati Egipti wá fun ẹgbẹta ṣekeli fadakà, ati ẹṣin kan fun ãdọjọ: bẹ̃ni nwọn si nmu wá pẹlu nipa ọwọ wọn fun gbogbo awọn ọba awọn ọmọ Hiti ati fun awọn ọba Siria.

## ORI 11.

ṢUGBỌN Solomoni ọba fẹràn ọ̀pọ ajeji obirin, pẹlu ọmọbirin Farao, awọn obirin ara Moabu, ti Ammoni, ti Edomu, ti Sidoni ati ti awọn ọmọ Hitti.
2 Awọn orilẹ-ède ti Oluwa wi fun awọn ọmọ-Israeli pe, Ẹnyin kò gbọdọ wọle tọ̀ wọn, bẹ̃ni awọn kò gbọdọ wọle tọ̀ nyin: nitõtọ nwọn o yi nyin li ọkàn pada si oriṣa wọn: Solomoni fà mọ awọn wọnyi ni ifẹ.
3 O si ni ọ̀dẹgbẹrin obirin, awọn ọmọ ọba, ati ọdunrun alè, awọn aya rẹ̀ si yi i li ọkàn pada.
4 O si ṣe, nigbati Solomoni di arugbo, awọn obirin rẹ̀ yi i li ọkàn pada si ọlọrun miran: ọkàn rẹ̀ kò si ṣe dede pẹlu Oluwa Ọlọrun rẹ̀, gẹgẹ bi ọkàn Dafidi, baba rẹ̀.
5 Nitori Solomoni tọ Aṣtoreti lẹhin, oriṣa awọn ara Sidoni, ati Milkomu, irira awọn ọmọ Ammoni.
6 Solomoni si ṣe buburu niwaju Oluwa, kò si tọ̀ Oluwa lẹhin ni pipé gẹgẹ bi Dafidi baba rẹ̀.
7 Nigbana ni Solomoni kọ́ ibi giga kan fun Kemoṣi, irira Moabu, lori oke ti mbẹ niwaju Jerusalemu, ati fun Moleki, irira awọn ọmọ Ammoni.
8 Bẹ̃li o si ṣe fun gbogbo awọn ajeji obirin rẹ̀, awọn ti nsun turari, ti nwọn si nrubọ fun oriṣa wọn.
9 Oluwa si binu si Solomoni, nitori ọkàn rẹ̀ yipada kuro lọdọ Oluwa Ọlọrun Israeli, ti o ti fi ara hàn a lẹrinmeji.
10 Ti o si paṣẹ fun u nitori nkan yi pe, Ki o má ṣe tọ̀ awọn ọlọrun miran lẹhin: ṣugbọn kò pa eyiti Oluwa fi aṣẹ fun u mọ́.
11 Nitorina Oluwa wi fun Solomoni pe, Nitori bi iwọ ti ṣe nkan yi, ti iwọ kò si pa majẹmu mi, ati aṣẹ mi mọ́, ti mo ti pa laṣẹ fun ọ, ni yiya emi o fà ijọba rẹ ya kuro lọwọ rẹ, emi o si fi i fun iranṣẹ rẹ.
12 Ṣugbọn emi kì yio ṣe e li ọjọ rẹ, nitori Dafidi baba rẹ; emi o fà a ya kuro lọwọ ọmọ rẹ.
13 Kiki pe emi kì yio fà gbogbo ijọba na ya; emi o fi ẹ̀ya kan fun ọmọ rẹ, nitori Dafidi iranṣẹ mi, ati nitori Jerusalemu ti mo ti yàn.
14 Oluwa si gbe ọta kan dide si Solomoni, Hadadi, ara Edomu: iru-ọmọ ọba li on iṣe ni Edomu.
15 O si ṣe, nigbati Dafidi wà ni Edomu, ati ti Joabu olori-ogun goke lọ lati sin awọn ti a pa, nigbati o pa gbogbo ọkọnrin ni Edomu.
16 Nitori oṣù mẹfa ni Joabu fi joko nibẹ ati gbogbo Israeli, titi o fi ké gbogbo ọkọnrin kuro ni Edomu:
17 Hadadi si sá, on ati awọn ara Edomu ninu awọn iranṣẹ baba rẹ̀ pẹlu rẹ̀, lati lọ si Egipti; ṣugbọn Hadadi wà li ọmọde.
18 Nwọn si dide kuro ni Midiani, nwọn si wá si Parani; nwọn si mu enia pẹlu wọn lati Parani wá: nwọn si wá si Egipti, sọdọ Farao ọba Egipti, o si fun u ni ile kan, o si yàn onjẹ fun u, o si fun u ni ilẹ.
19 Hadadi si ri oju-rere pupọ̀ niwaju Farao, o si fun u li arabirin aya rẹ̀, li aya, arabirin Tapenesi, ayaba.
20 Arabirin Tapenesi si bi Genubati ọmọ rẹ̀ fun u, Tapenesi si já a li ẹnu ọmu ni ile Farao: Genubati si wà ni ile Farao lãrin awọn ọmọ Farao,
21 Nigbati Hadadi si gbọ́ ni Egipti pe, Dafidi sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, ati pe Joabu olori-ogun si kú, Hadadi si wi fun Farao pe, rán mi lọ, ki emi ki o le lọ si ilu mi.
22 Nigbana ni Farao wi fun u pe, ṣugbọn kini iwọ ṣe alaini lọdọ mi, si kiyesi i, iwọ nwá ọ̀na lati lọ si ilu rẹ? O si wipe, Kò si nkan: ṣugbon sa jẹ ki emi ki o lọ.
23 Pẹlupẹlu Ọlọrun gbe ọta dide si i; ani Resoni, ọmọ Eliada, ti o ti sá kuro lọdọ Hadadeseri oluwa rẹ̀, ọba Soba:
24 On si ko enia jọ sọdọ ara rẹ̀, o si di olori-ogun ẹgbẹ́ kan, nigbati Dafidi fi pa wọn, nwọn si lọ si Damasku, nwọn ngbe ibẹ, nwọn si jọba ni Damasku.
25 On si ṣe ọta si Israeli ni gbogbo ọjọ

Digitized by Google

Solomoni, lẹhin ibi ti Hadadi ṣe: Resoni si korira Israeli, o si jọba lori Siria.
26 Ati Jeroboamu, ọmọ Nebati, ara Efrati ti Sereda, iranṣẹ Solomoni, orukọ iya ẹniti jiẹ Serua, obirin opó kan, on pẹlu gbe ọwọ soke si ọba.
27 Eyi si ni idi ohun ti o ṣe gbe ọwọ soke si ọba: Solomoni kọ́ Millo, o si di ẹya ilu Dafidi baba rẹ̀.
28 Ọkọnrin na, Jeroboamu, ṣe alagbara akọni: nigbati Solomoni si ri ọdọmọkọnrin na pe, oṣiṣẹ enia ni, o fi i ṣe olori gbogbo iṣẹ-iru ile Josefu.
29 O si ṣe li àkoko na, nigbati Jeroboamu jade kuro ni Jerusalemu, woli Ahijah ara Ṣilo ri i loju ọ̀na; o si wọ̀ agbáda titun; awọn meji pere li o si mbẹ ni oko:
30 Ahijah si gbà agbáda titun na ti a wà lara rẹ̀, o si fà a ya si ọ̀na mejila:
31 O si wi fun Jeroboamu pe, Iwọ mu ẹya mẹwa: nitori bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi pe, Wò o, emi o fa ijọba na ya kuro li ọwọ Solomoni, emi o si fi ẹya mẹwa fun ọ.
32 Ṣugbọn on o ni ẹya kan nitori Dafidi, iranṣẹ mi, ati nitori Jerusalemu, ilu ti mo ti yàn ninu gbogbo ẹya Israeli:
33 Nitori ti nwọn ti kọ̀ mi silẹ, nwọn si mbọ Astoreti, oriṣa awọn ara Sidoni, ati Kemoṣi, oriṣa awọn ara Moabu, ati Milkomu, oriṣa awọn ọmọ Ammoni, nwọn kò si rin li ọ̀na mi, lati ṣe eyiti o tọ́ li oju mi, ati lati pa aṣẹ mi ati idajọ mi mọ́, gẹgẹ bi Dafidi baba rẹ̀.
34 Ṣugbọn emi kì yio gba gbogbo ijọba na lọwọ rẹ̀, ṣugbọn emi o ṣe e li ọmọ-alade ni gbogbo ọjọ aiye rẹ̀, nitori Dafidi, iranṣẹ mi, ẹniti mo yàn, nitori o ti pa ofin mi ati aṣẹ mi mọ́:
35 Ṣugbọn emi o gba ijọba na li ọwọ ọmọ rẹ̀, emi o si fi i fun ọ, ani ẹya mẹwa.
36 Emi o si fi ẹya kan fun ọmọ rẹ̀, ki Dafidi iranṣẹ mi ki o le ni imọlẹ niwaju mi nigbagbogbo, ni Jerusalemu, ilu ti mo ti yàn fun ara mi lati fi orukọ mi sibẹ.
37 Emi o si mu ọ, iwọ o si jọba gẹgẹ bi gbogbo eyiti ọkàn rẹ nfẹ, iwọ o si jẹ ọba lori Israeli.
38 Yio si ṣe, bi iwọ o ba tẹtisilẹ si gbogbo eyiti mo paṣẹ fun ọ, ti iwọ o mã rin li ọ̀na mi, ti iwọ o si mã ṣe eyiti o tọ́ loju mi, lati pa aṣẹ mi ati ofin mi mọ́, gẹgẹ bi Dafidi iranṣẹ mi ti ṣe; emi o si wà pẹlu rẹ, emi o si kọ́ ile otitọ fun ọ, gẹgẹ bi emi ti kọ́ fun Dafidi, emi o si fi Israeli fun ọ.
39 Emi o si pọ́n iru-ọmọ Dafidi loju nitori eyi, ṣugbọn kì iṣe titi lai.
40 Nitorina Solomoni wá ọ̀na lati pa Jeroboamu. Jeroboamu si dide, o si sá lọ si Egipti si ọdọ Ṣiṣaki ọba Egipti, o si wà ni Egipti titi iku Solomoni.
41 Ati iyokù iṣe Solomoni ati gbogbo eyiti o ṣe, ati ọgbọ́n rẹ̀, a kò ha kọ wọn sinu iwe iṣe Solomoni bi?
42 Ọjọ ti Solomoni jọba ni Jerusalemu lori gbogbo Israeli jẹ ogoji ọdun.
43 Solomoni si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a si sin i ni ilu Dafidi baba rẹ̀: Rehoboamu, ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 12.

REHOBOAMU si lọ si Ṣekemu, nitori gbogbo Israeli li o wá si Ṣekemu lati fi i jẹ ọba.
2 O si ṣe, nigbati Jeroboamu, ọmọ Nebati, ti o wà ni Egipti sibẹ gbọ́, nitori ti o ti sá kuro niwaju Solomoni ọba, Jeroboamu si joko ni Egipti.
3 Nwọn si ranṣẹ pè e, ati Jeroboamu ati gbogbo ijọ Israeli wá, nwọn si sọ fun Rehoboamu wipe,
4 Baba rẹ sọ àjaga wa di wuwo: njẹ nitorina, ṣe ki isin baba rẹ ti o le, ati àjaga rẹ̀ ti o wuwo, ti o fi si wa li ọrùn, ki o fẹrẹ̀ diẹ, awa o si sin ọ.
5 O si wi fun wọn pe, Ẹ lọ na titi di ijọ mẹta, nigbana ni ki ẹ pada tọ̀ mi wá. Awọn enia na si lọ.
6 Rehoboamu ọba si ba awọn àgbagba, ti imã duro niwaju Solomoni, baba rẹ̀, nigbati o wà lãye, gbimọ̀ wipe, Imọran kili ẹnyin dá, ki emi ki o lè da awọn enia yi lohùn?
7 Nwọn si wi fun u pe, Bi iwọ o ba jẹ iranṣẹ fun awọn enia yi loni, ti iwọ o si sin wọn, ti iwọ o si da wọn lohùn, ati ti iwọ o sọ̀rọ rere fun wọn, nwọn o ṣe iranṣẹ rẹ titi lai.
8 Ṣugbọn o kọ̀ imọran awọn àgbagba ti nwọn ba a dá, o si ba awọn ipẹrẹ ti nwọn dagba pẹlu rẹ̀, ti nwọn si duro niwaju rẹ̀ gbimọ̀.
9 O si wi fun wọn pe, Imọran kini ẹnyin dá ki awa ki o le dá awọn enia yi lohùn, ti nwọn ba mi sọ wipe, Ṣe ki àjaga ti baba rẹ fi si wa lọrùn ki o fuyẹ diẹ?
10 Awọn ipẹrẹ ti o dagba pẹlu rẹ̀ wi fun u pe, Bayi ni ki iwọ ki o wi fun awọn enia yi ti nwọn ba ọ sọ wipe, Baba rẹ mu ki àjaga wa di wuwo, ṣugbọn iwọ mu ki o fuyẹ diẹ fun wa; bayi ni ki iwọ ki o sọ

Digitized by Google

fun wọn: Ọmọdirin mi yio nipọn jù ẹgbẹ́
baba mi lọ.
11 Njẹ nisisiyi, baba mi ti gbe àjaga
wuwo kà nyin, emi o si fi kún àjaga nyin:
baba mi ti fi paṣan nà nyin, ṣugbọn emi o
fi akẽke nà nyin.
12 Bẽni Jeroboamu ati gbogbo awọn enia
na wá sọdọ Rehoboamu ni ijọ kẹta, gẹgẹ bi
ọba ti dá wipe, Ẹ pada tọ̀ mi wá ni ijọ́
kẹta.
13 Ọba si da awọn enia li ohùn akọ, o si
kọ̀ ìmọran awọn àgbagba ti nwọn ba a dá.
14 O si sọ fun wọn gẹgẹ bi ìmọran awọn
ipẹrẹ wipe, Baba mi mu ki àjaga nyin ki o
wuwo, emi o si bù kún àjaga nyin: baba
mi fi paṣan nà nyin, ṣugbọn akẽke li emi o
fi nà nyin,
15 Ọba kò si fi eti si ti awọn enia na;
nitoriti ọ̀ran na ati ọwọ Oluwa wá ni, ki o
le mu ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ, ti Oluwa ti ọwọ Ahijah,
ara Ṣilo, sọ fun Jeroboamu, ọmọ Nebati.
16 Bẽni nigbati gbogbo Israeli ri pe, ọba
kò fetisi ti wọn, awọn enia na da ọba li
ohùn wipe: Ipín kini awa ni ninu Dafidi?
bẽni awa kò ni iní ninu ọmọ Jesse: Israeli,
ẹ pada si agọ nyin: njẹ mã bojuto ile rẹ,
Dafidi! Bẽni Israeli pada sinu agọ wọn.
17 Ṣugbọn awọn ọmọ Israeli ti ngbe inu
ilu Juda wọnni, Rehoboamu jọba lori
wọn.
18 Nigbana ni Rehoboamu ọba, ran
Adoramu ẹniti iṣe olori iṣẹ-iru; gbogbo
Israeli si sọ ọ li okuta, o si kú. Nitorina
Rehoboamu, ọba yara lati gun kẹkẹ́ rẹ̀, lati
sá lọ si Jerusalemu.
19 Bẽni Israeli ṣọtẹ̀ si ile Dafidi titi di
oni yi.
20 O si ṣe nigbati gbogbo Israeli gbọ́ pe
Jeroboamu tun pada bọ̀, ni nwọn ranṣẹ,
nwọn si pè e wá si ajọ, nwọn si fi i jọba
lori gbogbo Israeli: kò si ẹnikan ti o tọ̀ ile
Dafidi lẹhin, bikoṣe kiki ẹya Juda.
21 Nigbati Rehoboamu si wá si Jerusa-
lemu, o ko gbogbo ile Juda jọ, pẹlu ẹya
Benjamini, ọkẹ mẹsan enia ti a yàn, ti
nwọn iṣe ologun, lati ba ile Israeli ja, lati
mu ijọba na pada bọ̀ sọdọ Rehoboamu, ọmọ
Solomoni.
22 Ṣugbọn ọ̀rọ Ọlọrun tọ̀ Ṣemaiah, enia
Ọlọrun wá wipe,
23 Sọ fun Rehoboamu, ọmọ Solomoni,
ọba Juda, ati fun gbogbo ile Juda ati Ben-
jamini, ati fun iyokù awọn enia wipe,
24 Bayi li Oluwa wi, Ẹnyin kò gbọdọ
goke bẽli ẹnyin kò gbọdọ ba awọn arakọn-
rin nyin jà: ẹ pada olukuluku si ile rẹ̀;
nitori nkan yi ati ọdọ mi wá ni. Nwọn
si gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, nwọn si pada lati lọ,
gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa.
25 Nigbana ni Jeroboamu kọ́ Ṣekemu li
oke Efraimu o si ngbe inu rẹ̀; o si jade lati
ibẹ lọ, o si kọ́ Penueli.
26 Jeroboamu si wi li ọkàn rẹ̀ pe, Nisi-
siyi ni ijọba na yio pada si ile Dafidi:
27 Bi awọn enia wọnyi ba ngoke lọ lati
ṣe irubọ ni ile Oluwa ni Jerusalemu, ni-
gbana li ọkàn awọn enia yi yio tun yipada
sọdọ oluwa wọn, ani sọdọ Rehoboamu, ọba
Juda, nwọn o si pa mi, nwọn o si tun pada
tọ̀ Rehoboamu, ọba Juda lọ.
28 Ọba si gbìmọ, o si ya ẹgbọ̀rọ malu
wura meji, o si wi fun wọn pe, O pọ̀ju fun
nyin lati mã goke lọ si Jerusalemu: Isra-
eli, wò awọn ọlọrun rẹ, ti o mu ọ lati ilẹ
Egipti wá!
29 O si gbe ọkan kalẹ ni Beteli, ati eke-
ji li o fi si Dani.
30 Nkan yi si di ẹ̀ṣẹ: nitori ti awọn
enia lọ lati sìn niwaju ọkan, ani titi de
Dani.
31 O si kọ́ ile ibi giga wọnni, o si ṣe
alufa lati inu awọn enia, ti kì iṣe inu
awọn ọmọ Lefi.
32 Jeroboamu si dá àse silẹ li oṣu kẹjọ,
li ọjọ kẹdogun oṣu, gẹgẹ bi àse ti o wà ni
Juda, o si gun ori pẹpẹ na lọ: bẽni o si ṣe
ni Beteli, o rubọ si awọn ọmọ-malu ti o ṣe:
o si fi awọn alufa ibi giga wọnni ti o ti ṣẹ
si Beteli.
33 O si gun ori pẹpẹ na lọ ti o ti ṣe ni
Beteli li ọjọ kẹdogun oṣu kẹjọ, li oṣu ti o
rò li ọkàn ara rẹ̀; o si da àse silẹ fun awọn
ọmọ Israeli; o si gun ori pẹpẹ na lọ, lati
fi turari jona.

## ORI 13.

SI kiyesi i, enia Ọlọrun kan lati Juda wá
si Beteli nipa ọ̀rọ Oluwa: Jeroboamu
duro lẹba pẹpẹ lati fi turari jona.
2 O si kigbe si pẹpẹ na nipa ọ̀rọ Oluwa,
o si wipe, Pẹpẹ! pẹpẹ! bayi li Oluwa wi,
Kiyesi i, a o bi ọmọ kan ni ile Dafidi,
Josiah li orukọ rẹ̀; lori rẹ ni yio si fi awọn
alufa ibi giga wọnni ti nfi turari jona lori
rẹ rubọ, a o si sun egungun enia lori rẹ.
3 O si fun wọn li àmi kan li ọjọ kanna
wipe, Eyi li àmi ti Oluwa ti ṣe; Kiyesi i,
pẹpẹ na yio ya, ẽru ti mbẹ lori rẹ̀ yio si
danu.
4 O si ṣe, nigbati Jeroboamu ọba, gbọ́
ọ̀rọ enia Ọlọrun, ti o ti kigbe si pẹpẹ na, o

Digitized by Google

wipe, Ẹ mu u. Ọwọ́ rẹ̀ ti o nà si i, si gbẹ,
bẽni kò si le fa a pada sọdọ rẹ̀ mọ.
5 Pẹpẹ na si ya, ẽru na si danù kuro
ninu pẹpẹ na, gẹgẹ bi àmi ti enia Ọlọrun
ti fi fun u nipa ọ̀rọ Oluwa.
6 Ọba si dahùn, o si wi fun enia Ọlọrun
na pe, Tù Oluwa Ọlọrun rẹ loju nisisiyi, ki
o si gbadura fun mi, ki a ba le tun mu ọwọ́
mi bọ̀ sipo fun mi. Enia Ọlọrun na si tù
Ọlọrun loju, a si tun mu ọwọ́ ọba bọ̀ sipo
fun u, o si dàbi o ti wà ri.
7 Ọba si wi fun enia Ọlọrun na pe, Wá
ba mi lọ ilẹ, ki o si tù ara rẹ lara, emi o si
ta ọ li ọrẹ.
8 Enia Ọlọrun na si wi fun ọba pe, Bi
iwọ o ba fun mi ni idaji ile rẹ, emi kì yio
ba ọ lọ ile, emi kì yio si jẹ onjẹ, bẽni emi
kì yio si mu omi nihin yi.
9 Nitori bẹ̃ li a pa a laṣẹ fun mi nipa
ọ̀rọ Oluwa wipe, Máṣe jẹ onjẹ, má si ṣe mu
omi, bẽni ki o má si ṣe pada li ọ̀na kanna
ti o ba wá.
10 Bẹ̃ li o si ba ọ̀na miran lọ, kò si pada
li ọ̀na na ti o gbà wá si Beteli.
11 Woli àgba kan si ngbe Beteli: ọmọ
rẹ̀ de, o si rohin gbogbo iṣẹ ti enia Ọlọrun
na ti ṣe li ọjọ na ni Beteli fun u: ọ̀rọ ti o
sọ fun ọba, nwọn si sọ fun baba wọn.
12 Baba wọn si wi fun wọn pe, Ọna wo
li o gbà? Nitori awọn ọmọ rẹ̀ ti ri ọ̀na ti
enia Ọlọrun na gbà, ti o ti Juda wá.
13 O si wi fun awọn ọmọ rẹ̀ pe, Ẹ di
kẹtẹkẹtẹ ni gãri fun mi. Nwọn si di kẹtẹ-
kẹtẹ ni gãri fun u o si gùn u.
14 O si tẹ̀le enia Ọlọrun na lẹhin, o si ri
i, o joko labẹ igi nla kan: o si wi fun u pe
Iwọ li enia Ọlọrun na ti o ti Juda wá? On
si wipe, Emi ni.
15 O si wi fun u pe, Ba mi lọ ile, ki o si
jẹ onjẹ.
16 On si wipe, Emi kò lè pada lọ pẹlu
rẹ, bẽni emi kò lè ba ọ lọ: bẽni emi kì
o jẹ onjẹ, emi kì o si mu omi pẹlu rẹ
nihin yi.
17 Nitori ti a sọ fun mi nipa ọ̀rọ Oluwa
pe, Iwọ kò gbọdọ jẹ onjẹ, iwọ kò si gbọdọ
mu omi nibẹ, bẽni iwọ kò gbọdọ tun pada
lọ nipa ọ̀na ti iwọ ba wá.
18 O si wi fun u pe, Woli li emi pẹlu
gẹgẹ bi iwọ; angeli si sọ fun mi nipa ọ̀rọ
Oluwa wipe, Mu u ba ọ pada sinu ile rẹ, ki
o le jẹ onjẹ ki o si le mu omi. Ṣugbọn o
purọ fun u.
19 Bẹ̃ li o si ba a pada lọ, o si jẹ onjẹ ni
ile rẹ̀, o si mu omi.
20 O si ṣe, bi nwọn ti joko ti tabili, li
ọ̀rọ Oluwa tọ woli na wá ti o mu u padà
bọ̀:
21 O si kigbe si enia Ọlọrun ti o ti Juda
wá wipe, bayi li Oluwa wi: Niwọn bi iwọ
ti ṣe aigbọran si ẹnu Oluwa, ti iwọ kò si pa
aṣẹ na mọ ti Oluwa Ọlọrun rẹ pa fun ọ.
22 Ṣugbọn iwọ pada, iwọ si ti jẹ onjẹ,
iwọ si ti mu omi ni ibi ti Oluwa sọ fun ọ
pe, Máṣe jẹ onjẹ, ki o má si ṣe mu omi;
okú rẹ kì yio wá sinu iboji awọn baba rẹ.
23 O si ṣe, lẹhin igbati o ti jẹ onjẹ, ati
lẹhin igbati o ti mu, li o di kẹtẹkẹtẹ ni
gari fun u, eyini ni, fun woli ti o ti mu
pada bọ̀.
24 Nigbati o si lọ tan, kiniun kan pade
rẹ̀ li ọ̀na, o si pa a: a si gbe okú rẹ̀ sọ si
oju ọ̀na, kẹtẹkẹtẹ si duro tì i, kiniun pẹlu
duro tì okú na.
25 Si kiyesi i, awọn enia nkọja, nwọn ri
pe, a gbe okú na sọ si oju ọ̀na, kiniun na si
duro tì okú na: nwọn si wá, nwọn si sọ ọ
ni ilu ti woli àgba na ngbe.
26 Nigbati woli ti o mu u lati ọ̀na pada
bọ̀ gbọ́, o wipe, Enia Ọlọrun na ni, ti o
ṣọ̀tẹ si Oluwa: nitorina li Oluwa fi i le
kiniun lọwọ, ti o si fà a ya, ti o si pa a,
gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, ti o ti sọ fun u.
27 O si wi fun awọn ọmọ rẹ̀ pe, Ẹ di
kẹtẹkẹtẹ ni gãri fun mi. Nwọn si di i ni
gãri.
28 O si lọ, o si ri, a gbé okú rẹ̀ sọ si
oju ọ̀na, ati kẹtẹkẹtẹ, ati kiniun duro ti
okú na, kiniun kò jẹ okú na, bẽni kò fà
kẹtẹkẹtẹ na ya.
29 Woli na mu okú enia Ọlọrun na, o si
gbé e lori kẹtẹkẹtẹ na, o si mu u pada bọ̀:
woli àgba na si wá si ilu, lati ṣọ̀fọ, ati lati
sin i.
30 O si tẹ okú rẹ̀ sinu iboji ara rẹ̀:
nwọn si ṣọ̀fọ lori rẹ̀, pe: O ṣe, arakọnrin
mi!
31 O si ṣe, lẹhin igbati o ti sinkú rẹ̀ tan,
o si sọ fun awọn ọmọ rẹ̀ wipe, Nigbati mo
ba kú, nigbana ni ki ẹ sinkú mi ni iboji
ninu eyiti a sin enia Ọlọrun; ẹ tẹ́ egungun
mi lẹba egungun rẹ̀:
32 Nitori ni ṣiṣẹ, ọ̀rọ ti o kigbe nipa ọ̀rọ
Oluwa si pẹpẹ na ni Beteli, ati si gbogbo
ile ibi giga ti mbẹ ni gbogbo ilu Samaria,
yio ṣe dandan.
33 Lẹhin nkan yi, Jeroboamu kò pada
kuro ninu ọ̀na ibi rẹ̀, ṣugbọn o tun mu ninu
awọn enia ṣe alufa ibi giga wọnni: ẹnikẹni
ti o ba fẹ, a yà a sọtọ̀ on a si di alufa ibi
giga wọnni.
34 Nkan yi si di ẹ̀ṣẹ si ile Jeroboamu,

Digitized by Google

ani lati ke e kuro, ati lati pa a run kuro
lori ilẹ.

## ORI 14.

LI àkoko na, Abijah ọmọ Jeroboamu
ṣàisan.
2 Jeroboamu si wi fun aya rẹ̀ pe, Dide,
emi bẹ̀ ọ, si pa ara rẹ dà, ki a má ba le mọ̀
ọ li aya Jeroboamu; ki o si lọ si Ṣilo: ki-
yesi i, nibẹ li Ahijah, woli wà, ti o sọ fun
mi pe, emi o jọba lori enia yi.
3 Ki o si mu ìṣu àkara mẹwa li ọwọ́ rẹ,
ati akara wẹwẹ, ati igo oyin, ki o si lọ
sọdọ rẹ̀: on o si wi fun ọ bi yio ti ri fun
ọmọde na.
4 Aya Jeroboamu si ṣe bẹ̃, o si dide, o si
lọ si Ṣilo, o si wá si ile Ahijah. Ṣugbọn
Ahijah kò riran; nitoriti oju rẹ̀ fọ́ nitori
ogbó rẹ̀.
5 Oluwa si wi fun Ahijah, pe, Kiyesi i,
aya Jeroboamu mbọ̀ wá bère ohun kan
lọwọ rẹ niti ọmọ rẹ̀: nitori ti o ṣàisan:
bayi bayi ni ki iwọ ki o wi fun u: yio
si ṣe, nigbati o ba wọle, yio ṣe ara rẹ̀ bi
ẹlomiran.
6 Bẹ̃ li o si ri, nigbati Ahijah gbọ́ iró
ẹsẹ rẹ̀, bi o ti mbọ̀ wá li ẹnu ọ̀na, on si
wipe, Wọle wá, iwọ, aya Jeroboamu, ẽṣe ti
iwọ fi ṣe ara rẹ bi ẹlomiran? nitori iṣẹ
wuwo li a fi rán mi si ọ.
7 Lọ, sọ fun Jeroboamu, pe, Bayi li
Oluwa Ọlọrun Israeli wi, Nitori bi mo ti
gbé ọ ga lati inu awọn enia, ti mo si fi ọ jẹ
olori Israeli enia mi.
8 Ti mo si fà ijọba ya kuro ni ile Dafidi,
mo si fi i fun ọ: sibẹ iwọ kò ri bi Dafidi
iranṣẹ mi, ẹniti o pa ofin mi mọ, ti o si tọ̀
mi lẹhin tọkàntọkàn rẹ̀, lati ṣe kiki eyi ti
o tọ li oju mi:
9 Ṣugbọn iwọ ti ṣe buburu jù gbogbo
awọn ti o ti wà ṣaju rẹ: nitori iwọ ti lọ,
iwọ si ti ṣe awọn ọlọrun miran, ati ere
didà, lati ru ibinu mi, ti iwọ si ti gbé mi
sọ si ẹhin rẹ:
10 Nitorina, kiyesi i, emi o mu ibi wá
si ile Jeroboamu, emi o ke gbogbo ọdọmọ-
kọnrin kuro lọdọ Jeroboamu, ati ọmọ-ọdọ
ati omnira ni Israeli, emi o si mu awọn ti
o kù ni ile Jeroboamu kuro, gẹgẹ bi enia
ti ikó igbẹ kuro, titi gbogbo rẹ̀ yio fi tan.
11 Ẹni Jeroboamu ti a ba kú ni ilu li
awọn ajá yio jẹ: ati ẹniti o ba kú ni igbẹ
li awọn ẹiyẹ oju-ọrun yio jẹ: nitori Oluwa
ti sọ ọ.
12 Nitorina, iwọ dide, lọ si ile rẹ:
nigbati ẹsẹ rẹ ba si wọ̀ ilu, ọmọ na yio
kú.
13 Gbogbo Israeli yio si ṣọ̀fọ rẹ̀, nwọn o
si sin i; nitori kiki on nikan li ẹniti yio
wá si isa-okú ninu ẹniti iṣe ti Jeroboamu,
nitori lọdọ rẹ̀ li a ri ohun rere diẹ sipa
Oluwa, Ọlọrun Israeli, ni ile Jeroboamu.
14 Oluwa yio si gbé ọba kan dide lori
Israeli, ti yio ke ile Jeroboamu kuro li ọjọ
na: ṣugbọn kini? ani nisisiyi!
15 Nitoriti Oluwa yio kọlu Israeli bi a
ti imì iye ninu omi, yio si fa Israeli tu
kuro ni ilẹ rere yi, ti o ti fi fun awọn baba
wọn, yio si fọ́n wọn ka kọja odò na, nito-
riti nwọn ṣe ere oriṣa wọn, nwọn si nru
ibinu Oluwa.
16 Yio si kọ̀ Israeli silẹ nitori ẹ̀ṣẹ Jero-
boamu, ẹniti o ṣẹ̀, ti o si mu Israeli dẹṣẹ.
17 Aya Jeroboamu si dide, o si lọ, o si
de Tira: nigbati o si wọ̀ iloro ile, ọmọde
na si kú;
18 Nwọn si sin i; gbogbo Israeli si ṣọ̀fọ
rẹ̀, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, ti o sọ nipa ọwọ́
iranṣẹ rẹ̀, Ahijah woli.
19 Ati iyokù iṣe Jeroboamu, bi o ti
jagun, ati bi o ti jọba, kiyesi i, a kọ wọn
sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Israeli.
20 Awọn ọjọ ti Jeroboamu jọba jẹ ọdun
mejilelogun, o si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀.
Nadabu ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
21 Rehoboamu, ọmọ Solomoni, si jọba
ni Juda: Rehoboamu jẹ ẹni ọdun mọkan-
lelogun nigbati o bẹrẹ si ijọba, o si jọba li
ọdun mọkanlelogun ni Jerusalemu, ilu ti
Oluwa ti yàn ninu gbogbo ẹya Israeli, lati
fi orukọ rẹ̀ sibẹ. Orukọ iya rẹ̀ si ni Naama,
ara Ammoni.
22 Juda si ṣe buburu niwaju Oluwa,
nwọn si fi ẹ̀ṣẹ wọn mu u jowu jù gbogbo
eyiti baba wọn ti ṣe, ti nwọn si ti dá.
23 Nitori awọn pẹlu kọ́ ibi giga fun ara
wọn, ati ere, ati igbo-oriṣa lori gbogbo oke
giga, ati labẹ gbogbo igi tutu.
24 Awọn ti nhùwa panṣaga mbẹ ni ilẹ
na: nwọn si ṣe gẹgẹ bi gbogbo ohun irira
awọn orilẹ-ède ti Oluwa lé jade kuro niwaju
awọn ọmọ Israeli.
25 O si ṣe li ọdun karun Rehoboamu
ọba, Ṣiṣaki, ọba Egipti goke wá si Jerusa-
lemu:
26 O si kó iṣura ile Oluwa lọ, ati iṣura
ile ọba; ani gbogbo rẹ̀ li o kó lọ: o si kó
gbogbo asà wura ti Solomoni ti ṣe lọ.
27 Rehoboamu ọba si ṣe asà idẹ ni ipò
wọn, o si fi wọn si ọwọ́ olori awọn oluṣọ ti
nṣọ ilẹkun ile ọba.

Digitized by Google

28 Bẹ̀li o si ri, nigbati ọba ba nlọ si ile
Oluwa, nwọn a rù wọn, nwọn a si mu wọn
pada sinu yara olușọ.
29 Iyokù ișe Rehoboamu, ati gbogbo
ohun ti o șe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
ọjọ awọn ọba Juda?
30 Ogun si wà lãrin Rehoboamu ati
Jeroboamu li ọjọ wọn gbogbo.
31 Rehoboamu si sùn pẹlu awọn baba
rẹ̀, a si sin i pẹlu awọn baba rẹ̀ ni ilu
Dafidi. Orukọ iya rẹ̀ si ni Naama, ara
Ammoni. Abijah, ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 15.

NJẸ li ọdun kejidilogun Jeroboamu ọba,
ọmọ Nebati, Abijah jọba lori Juda.
2 Ọdun mẹta li o jọba ni Jerusalemu:
orukọ iya rẹ̀ si ni Maaka, ọmọbirin Abișa-
lomu.
3 O si rin ninu gbogbo ẹ̀șẹ baba rẹ̀, ti o
ti dá niwaju rẹ̀: ọkàn rẹ̀ kò si pé pẹlu
Oluwa Ọlọrun rẹ̀ gẹgẹ bi ọkàn Dafidi baba
rẹ̀.
4 Șugbọn nitori Dafidi li Oluwa Ọlọrun
rẹ̀ fun u ni imọlẹ kan ni Jerusalemu, lati
gbé ọmọ rẹ̀ ró lẹhin rẹ̀, ati lati fi idi Jeru-
salemu mulẹ:
5 Nitori Dafidi șe eyi ti o tọ li oju Olu-
wa, kò si yipada kuro ninu gbogbo eyiti o
pașẹ fun u li ọjọ aiye rẹ̀ gbogbo, bikoșe ni
kiki ọ̀ran Uria, ara Hitti.
6 Ogun si wà lãrin Rehoboamu ati Jero-
boamu li ọjọ aiye rẹ̀ gbogbo.
7 Njẹ iyokù ișe Abijah ati gbogbo eyiti
o șe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn
ọba Juda? Ogun si wà lãrin Abijah ati
Jeroboamu.
8 Abijah si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀;
nwọn si sin i ni ilu Dafidi: Asa, ọmọ rẹ̀,
si jọba ni ipò rẹ̀.
9 Ati li ogun ọdun Jeroboamu ọba
Israeli, ni Asa jọba lori Juda.
10 Ọdun mọkanlelogoji li o jọba ni
Jerusalemu, orukọ iya nla rẹ̀ si ni Maaka,
ọmọbirin Abișalomu.
11 Asa si șe eyiti o tọ loju Oluwa, bi
Dafidi baba rẹ̀.
12 O si mu awọn ti nșe panșaga kuro ni
ilẹ na, o si kó gbogbo ere ti awọn baba rẹ̀
ti șe kuro.
13 Ati Maaka iya rẹ̀ papã, li o si mu
kuro lati má șe ayaba, nitori ti o yá ere
kan fun orișa rẹ̀; Asa si ke ere na kuro; o
si daná sun u nibi odò Kidroni.
14 Șugbọn ibi giga wọnnì ni a kò mu
kuro; sibẹ ọkàn Asa pé pẹlu Oluwa li ọjọ
aiye rẹ̀ gbogbo.
15 O si mu ohun-mimọ́ wọnnì ti baba
rẹ̀, ati ohun-mimọ́ wọnnì ti on tikararẹ̀ wọ
ile Ọluwa, fadaka ati wura, ati ohun-elo
wọnnì.
16 Ogun si wà lãrin Asa ati Baașa, ọba
Israeli ni gbogbo ọjọ wọn.
17 Baașa, ọba Israeli, si goke lọ si Juda,
o si kọ́ Rama, nitori ki o má le jẹ ki ẹni-
kẹni ki o jade tabi ki o wọle tọ Asa ọba lọ.
18 Nigbana ni Asa mu gbogbo fadaka,
ati wura ti o kù ninu ișura ile Oluwa, ati
ișura ile ọba, o si fi wọn si ọwọ́ awọn iranșẹ
rẹ̀: Asa ọba si rán wọn si ọdọ Benhadadi,
ọmọ Tabrimoni, ọmọ Hesioni, ọba Siria, ti
o ngbe Damasku, wipe,
19 Jẹ ki majẹmu ki o wà lãrin emi ati
iwọ, lãrin baba mi ati baba rẹ, kiye si i,
emi ran ọrẹ fadaka ati wura si ọ; wá, ki o
si dà majẹmu rẹ pẹlu Baașa, ọba Israeli, ki
o je lọ kuro lọdọ mi.
20 Bẹ̀ni Benhadadi fi eti si ti Asa ọba,
o si rán awọn alagbara olori-ogun ti o ni,
si ilu Israeli wọnnì, o si kọlu Ijoni, ati
Dani ati Abel-bet-maaka, ati gbogbo Ken-
neroti pẹlu gbogbo ilẹ Naftali.
21 O si șe, nigbati Baașa gbọ́, o si șiwọ
ati kọ́ Rama, o si ngbe Tirsa.
22 Nigbana ni Asa ọba kede ká gbogbo
Juda, kò da ẹnikan si: nwọn si kó okuta
Rama kuro, ati igi rẹ̀, ti Baașa fi kọle: Asa
ọba si fi wọn kọ́ Geba ti Benjamini, ati
Mispa.
23 Iyokù gbogbo ișe Asa, ati gbogbo
agbara rẹ̀ ati gbogbo ohun ti o șe, ati ilu
wọnni ti o kọ́, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
ọjọ awọn ọba Juda? Șugbọn li akoko
ogbó rẹ̀, àrun șe e li ẹsẹ rẹ̀.
24 Asa si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a si
sin i pẹlu awọn baba rẹ̀ ni ilu Dafidi baba
rẹ̀. Jehoșafati, ọmọ rẹ̀, si jọba ni ipò rẹ̀.
25 Nadabu ọmọ Jeroboamu si bẹ̀rẹ si
ijọba lori Israeli li ọdun keji Asa, ọba
Juda, o si jọba lori Israeli li ọdun meji.
26 O si șe buburu niwaju Oluwa, o si
rìn li ọ̀na baba rẹ̀, ati ninu ẹ̀șẹ rẹ̀ eyiti o
mu Israeli șẹ̀.
27 Baașa ọmọ Ahijah ti ilẹ Issakari, si
dìtẹ si i; Baașa kọlu u ni Gibbetoni ti
awọn ara Filistia: nitori Nadabu ati gbo-
gbo Israeli dó ti Gibbetoni.
28 Ani li ọdun kẹta ti Asa ọba Juda, ni
Baașa pa a, o si jọba ni ipò rẹ̀.
29 O si șe, nigbati o jọba, o kọlu gbo-
gbo ile Jeroboamu; kò kù fun Jeroboamu

Digitized by Google

ẹniti nmí, titi o fi run u, gẹgẹ bi ọ̀rọ Ọluwa,
ti o sọ nipa ọwọ́ iranṣẹ rẹ̀, Ahijah ara Ṣilo:
30 Nitori ẹ̀ṣẹ Jeroboamu ti o ṣẹ̀, ti o si
mu ki Israeli ṣẹ̀, nipa imunibinu rẹ̀, eyiti o
fi mu ki Oluwa Ọlọrun Israeli ki o binu.
31 Ati iyokù iṣe Nadabu, ati gbogbo
ohun ti o ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
ọjọ awọn ọba Israeli.
32 Ogun si wà, lãrin Asa ati Baaṣa ọba
Israeli ni gbogbo ọjọ wọn.
33 Li ọdun kẹta Asa, ọba Juda, ni
Baaṣa, ọmọ Ahijah bẹ̀rẹ si ijọba lori gbogbo
Israeli ni Tirsa, li ọdun mẹrinlelogun.
34 O si ṣe buburu niwaju Oluwa, o si
rìn li ọ̀na Jeroboamu, ati ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, eyiti
o mu Israeli ṣẹ̀.

## ORI 16.

O SI ṣe, ọ̀rọ Oluwa, tọ Jehu, ọmọ Hanani
wá, si Baaṣa wipe,
2 Bi o ti ṣepe mo gbé ọ ga lati inu ẽkuru
wá, ti mo si ṣe ọ li olori Israeli, enia mi;
iwọ si rìn li ọ̀na Jeroboamu, iwọ si ti mu
ki Israeli enia mi ki o ṣẹ̀, lati fi ẹ̀ṣẹ wọn
mu mi binu;
3 Kiyesi i, emi o mu iran Baaṣa, ati iran
ile rẹ̀ kuro; emi o si ṣe ile rẹ bi ile Jero-
boamu, ọmọ Nebati.
4 Ẹni Baaṣa ti o ba kú ni ilu li awọn
ajá yio jẹ; ati ẹni rẹ̀ ti o kú ni oko li ẹiyẹ
oju-ọrun o jẹ.
5 Ati iyokù iṣe Baaṣa, ati ohun ti o ṣe,
ati agbara rẹ̀, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
ọjọ awọn ọba Israeli.
6 Baaṣa si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a si
sin i ni Tirsa: Ela, ọmọ rẹ̀, si jọba ni ipò rẹ̀.
7 Ati pẹlu nipa ọwọ́ Jehu wọli, ọmọ
Hanani, li ọ̀rọ Oluwa de si Baaṣa, ati si
ile rẹ̀, ani nitori gbogbo ibi ti o ṣe niwaju
Oluwa, ni fifi iṣẹ ọwọ́ rẹ̀ mu u binu, ati
wiwà bi ile Jeroboamu, ati nitori ti o pa a.
8 Li ọdun kẹrindilọgbọn Asa, ọba Juda,
ni Ela, ọmọ Baaṣa, bẹ̀rẹ si ijọba lori Israeli
ni Tirsa li ọdun meji.
9 Ati iranṣẹ rẹ̀ Simri, olori idaji kẹkẹ́
rẹ̀, dìtẹ rẹ̀, nigbati o ti wà di Tirsa, o si
mu amupara ni ile Arsa, iriju ile rẹ̀ ni Tirsa.
10 Simri si wọle o si kọlù u, o si pa a,
li ọdun kẹtadilọgbọn Asa, ọba Juda, o si
jọba ni ipò rẹ̀.
11 O si ṣe, nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, bi o ti
joko li ori itẹ rẹ̀, o lù gbogbo ile Baaṣa pa:
kò kù ọmọde ọkọnrin kan silẹ, ati awọn
ibatan rẹ̀ ati awọn ọrẹ́ rẹ̀.
12 Bayi ni Simri pa gbogbo ile Baaṣa
run, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, ti o sọ si Baaṣa
nipa ọwọ́ Jehu woli,
13 Nitori gbogbo ẹ̀ṣẹ Baaṣa, ati Ela,
ọmọ rẹ̀, nipa eyiti nwọn ṣẹ̀, ati nipa eyiti
nwọn mu Israeli ṣẹ̀, ni fifi ohun-asan wọn
wọnnì mu ki Oluwa, Ọlọrun Israeli binu.
14 Ati iyokù iṣe Ela, ati gbogbo ohun
ti o ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ
awọn ọba Israeli?
15 Li ọdun kẹtadilọgbọn Asa, ọba Juda,
ni Simri jọba ijọ meje ni Tirsa. Awọn
enia si do tì Gibbetoni, ti awọn ara
Filistia.
16 Awọn enia ti o dotì gbọ́ wipe, Simri
ditẹ̀ o si ti pa ọba pẹlu: nitorina gbogbo
Israeli fi Omri, olori ogun, jẹ ọba lori
Israeli li ọjọ na ni ibudo.
17 Omri si goke lati Gibbetoni lọ, ati
gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀, nwọn si do tì Tirsa.
18 O si ṣe, nigbati Simri mọ̀ pe a gba
ilu, o wọ inu ãfin ile ọba lọ, o si tẹ iná bọ
ile ọba lori ara rẹ̀, o si kú.
19 Nitori ẹ̀ṣẹ wọnni ti o da, ni ṣiṣe
buburu niwaju Oluwa, ni ririn li ọ̀na Jero-
boamu ati ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o da, lati mu ki
Israeli ki o ṣẹ̀.
20 Ati iyokù iṣe Simri, ati ọtẹ rẹ̀ ti o dì,
a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba
Israeli?
21 Nigbana li awọn enia Israeli da
meji; apakan awọn enia ntọ̀ Tibni, ọmọ
Ginati lẹhin, lati fi i jọba, apakan si ntọ̀
Omri lẹhin.
22 Ṣugbọn awọn enia ti ntọ̀ Omri lẹhin
bori awọn ti ntọ̀ Tibni, ọmọ Ginati lẹhin:
bẽni Tibni kú, Omri si jọba.
23 Li ọdun kọkanlelọgbọn Asa, ọba
Juda, ni Omri bẹ̀rẹ si ijọba lori Israeli
ọdun mejila: ọdun mẹfa li o jọba ni Tirsa.
24 O si rà oke Samaria lọwọ Semeri ni
talenti meji fadaka, o si tẹdo lori oke na,
o si pe orukọ ilu na ti o tẹ̀do ni Samaria
nipa orukọ Semeri, oluwa oke Samaria.
25 Ṣugbọn Omri ṣe buburu li oju Oluwa,
o si ṣe buburu jù gbogbo awọn ti o wà saju
rẹ̀.
26 Nitori ti o rìn ni gbogbo ọ̀na Jero-
boamu, ọmọ Nebati, ati ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, eyiti
o mu Israeli ṣẹ̀, lati fi ohun-asan wọn wọnni
mu Oluwa, Ọlọrun Israeli binu.
27 Ati iyokù iṣe Omri ti o ṣe, ati agbara
rẹ̀ ti o fi hàn, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
ọjọ awọn ọba Israeli?
28 Omri si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a si
sin i ni Samaria: Ahabu ọmọ rẹ̀ si jọba ni
ipò rẹ̀.

Digitized by Google

29 Ati li ọdun kejidilogoji Asa, ọba
Juda, ni Ahabu, ọmọ Omri, bẹ̀rẹ si jọba
lori Israeli: Ahabu, ọmọ Omri, si jọba
lori Israeli ni Samaria li ọdun mejilelogun,
30 Ahabu, ọmọ Omri, si ṣe buburu li
oju Oluwa jù gbogbo awọn ti o wà ṣaju
rẹ̀ lọ.
31 O si ṣe, bi ẹnipe o ṣe ohun kekere
fun u lati ma rìn ninu ẹ̀ṣẹ Jeroboamu, ọmọ
Nebati, o si mu Jesebeli, ọmọbirin Etbaali,
ọba awọn ara Sidoni li aya, o si lọ, o si sin
Baali, o si bọ ọ.
32 O si tẹ pẹpẹ kan fun Baali ninu ile
Baali, ti o kọ́ ni Samaria.
33 Ahabu si ṣe ere oriṣa kan; Ahabu si
ṣe jù gbogbo awọn ọba Israeli lọ, ti o wà
ṣaju rẹ̀, lati mu ki Oluwa Ọlọrun Israeli
binu.
34 Li ọjọ rẹ̀ ni Hieli, ara Beteli, kọ́
Jeriko: o fi ipilẹ rẹ̀ le ilẹ ni Abiramu,
akọbi rẹ̀, o si gbé awọn ilẹkun ibode rẹ̀ kọ́
ni Segubu abikẹhin rẹ̀, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa,
ti o ti ipa Joṣua, ọmọ Nuni sọ.

## ORI 17.

ELIJAH ara Tiṣbi, lati inu awọn olugbe
Gileadi, wi fun Ahabu pe, Bi Oluwa
Ọlọrun ti wà, niwaju ẹniti emi duro, kì
yio si ìri tabi òjo li ọdun wọnyi, ṣugbọn
gẹgẹ bi ọ̀rọ mi.
2 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ ọ wá wipe:
3 Kuro nihin, ki o si kọju siha ila-õrun,
ki o si fi ara rẹ pamọ nibi odò Keriti, ti
mbẹ niwaju Jordani.
4 Yio si ṣe, iwọ o mu ninu odò na; mo
si ti paṣẹ fun awọn ẹiyẹ iwò lati ma bọ́ ọ
nibẹ.
5 O si lọ, o si ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa: o
si lọ, o si ngbe ẹ̀ba odò Keriti, ti mbẹ ni-
waju Jordani.
6 Awọn ẹiyẹ iwò si mu akara pẹlu ẹran
fun u wá li owurọ, ati akara ati ẹran li alẹ:
on si mu ninu odò na.
7 O si ṣe lẹhin ọjọ wọnni, odò na si gbẹ,
nitoriti kò si òjo ni ilẹ na.
8 Ọ̀rọ Oluwa tọ̀ ọ wá wipe,
9 Dide, lọ si Sarefati ti Sidoni, ki o si
ma gbe ibẹ: kiyesi i, emi ti paṣẹ fun obi-
rin opó kan nibẹ lati ma bọ́ ọ.
10 On si dide, o si lọ si Sarefati. Ni-
gbati o si de ibode ilu na, kiyesi i, obirin
opó kan nṣa igi jọ nibẹ: o si ke si i, o si
wipe, Jọ̃, bu omi diẹ fun mi wá ninu ohun-
elo, ki emi ki o le mu.
11 Bi o si ti nlọ bù u wá, o ke si i, o si
wipe, Jọ̃, mu okele onjẹ diẹ fun mi wá
lọwọ rẹ.
12 On si wipe, Bi Oluwa Ọlọrun rẹ ti wà,
emi kò ni àkara, ṣugbọn ikunwọ iyẹfun
ninu ìkoko, ati ororo diẹ ninu kòlobo: si
kiyesi i, emi nṣa igi meji jọ, ki emi ki o le
wọle lọ, ki emi ki o si pese rẹ̀ fun mi, ati
fun ọmọ mi, ki awa le jẹ ẹ, ki a si kú.
13 Elijah si wi fun u pe, Má bẹ̀ru; lọ,
ki o si ṣe gẹgẹ bi o ti wi; ṣugbọn ki o tète-
kọ ṣe àkara kekere kan fun mi ninu rẹ̀ na,
ki o si mu u fun mi wá, lẹhin na, ki o ṣe
tirẹ ati ti ọmọ rẹ:
14 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli
wi: Ikoko iyẹfun na kì yio ṣòfo, bẹni kò-
lobo ororo na kì yio gbẹ, titi di ọjọ ti
Oluwa yio rọ̀ òjo si ori ilẹ.
15 O si lọ, o ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ Elijah: ati
on ati obirin na, ati ile rẹ̀ jẹ li ọjọ pupọ̀.
16 Ikoko iyẹfun na kò ṣòfo, bẹ̃ni kòlobo
ororo na kò gbẹ, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, ti o ti
ipa Elijah sọ.
17 O si ṣe lẹhin nkan wọnyi, ni ọmọ
obirin na, iya ile na, ṣe aisàn; aisàn rẹ̀ na
si le to bẹ̃, ti kò kù ẹmi ninu rẹ̀.
18 On si wi fun Elijah pe, Kili o ṣe mi
ṣe ọ, Iwọ enia Ọlọrun? iwọ ha tọ̀ mi wá
lati mu ẹ̀ṣẹ mi wá si iranti, ati lati pa mi
li ọmọ?
19 On si wi fun u pe, Gbé ọmọ rẹ fun
mi. Elijah si yọ ọ jade li aiya rẹ̀, o si gbé
e lọ si iyara-òke ile nibiti on ngbe, on si tẹ́
ẹ si ori akete tirẹ̀.
20 O si kepe OLUWA, o si wipe, OLUWA
Ọlọrun mi, iwọ ha mu ibi wá ba opó na
pẹlu lọdọ ẹniti emi nṣe atipo, ni pipa ọmọ
rẹ̀?
21 On si nà ara rẹ̀ lori ọmọde na li ẹrin-
mẹta, o si kepe Oluwa, o si wipe, Oluwa
Ọlọrun mi, emi bẹ̀ ọ, jẹ ki ẹmi ọmọde yi ki
o tun padà wá sinu rẹ̀.
22 Oluwa si gbọ́ ohũn Elijah; ẹmi ọmọ-
de na si tun padà wá sinu rẹ̀, o si sọji.
23 Elijah si mu ọmọde na, o si mu u
sọkalẹ lati inu iyara-òke na wá sinu ile, o
si fi i le iya rẹ̀ lọwọ: Elijah si wipe, Wò o,
ọmọ rẹ yè.
24 Obirin na si wi fun Elijah pe, nisisiyi
nipa eyi li emi mọ̀ pe, enia Ọlọrun ni iwọ
iṣe, ati pe, ọ̀rọ Oluwa li ẹnu rẹ, otitọ ni.

## ORI 18.

O SI ṣe, lẹhin ọjọ pupọ, ọ̀rọ Oluwa tọ
Elijah wá lọdun kẹta, wipe, Lọ, fi ara
rẹ hàn Ahabu; emi o si rọ̀ òjo sori ilẹ.

Digitized by Google

2 Elijah si lọ ifi ara rẹ̀ han Ahabu.
Iyan nla si mu ni Samaria.
3 Ahabu si pe Obadiah, ti iṣe olori ile
rẹ̀. Njẹ Obadiah bẹ̀ru Oluwa gidigidi:
4 O si ṣe, nigbati Jesebeli ke awọn woli
Oluwa kuro, ni Obadiah mu ọgọrun woli,
o si fi wọn pamọ li aradọta ni iho okuta;
o si fi àkara pẹlu omi bọ́ wọn.
5 Ahabu si wi fun Obadiah pe, Rin ilẹ
lọ, si orisun omi gbogbo, ati si odò gbogbo:
bọya awa le ri koriko lati gbà awọn ẹṣin
ati awọn ibãka là, ki a má ba ṣòfo awọn
ẹranko patapata.
6 Nwọn si pin ilẹ na lãrin ara wọn, lati
là a ja: Ahabu gba ọ̀na kan lọ fun ara
rè, Obadiah si gba ọ̀na miran lọ fun ara
rẹ̀.
7 Nigbati Obadiah si wà li ọ̀na, kiyesi
i, Elijah pade rẹ̀: nigbati o mọ̀ ọ, o si
doju rẹ̀ bolẹ, o si wipe, Iwọ, oluwa mi Eli-
jah nìnì?
8 O si da a lohùn pe, Emi ni: lọ, sọ
fun oluwa rẹ pe, Wò o, Elijah mbẹ nihin.
9 On si wipe, Ẹṣẹ kini mo ha dá, ti iwọ
fẹ fi iranṣẹ rẹ le Ahabu lọwọ lati pa mi?
10 Bi oluwa Ọlọrun rẹ ti wà, kò si orilẹ-
ède tabi ijọba kan, nibiti oluwa mi kò
ranṣẹ de lati wò ọ: nigbati nwọn ba si
wipe, Kò si; on a mu ki ijọba tabi orilẹ-
ède na bura pe: awọn kò ri ọ.
11 Nisisiyi iwọ si wipe, Lọ, sọ fun oluwa
rẹ pe, Wò o, Elijah mbẹ nihin;
12 Yio si ṣe bi emi o ti lọ kuro li ọdọ rẹ,
Ẹmi Oluwa yio si gbe ọ lọ si ibi ti emi kò
mọ̀; nigbati mo ba si de, ti mo si wi fun
Ahabu, ti kò ba si ri ọ, on o pa mi:
ṣugbọn emi, iranṣẹ rẹ, bẹ̀ru Oluwa lati
igba ewe mi wá.
13 A kò ha sọ fun oluwa mi, ohun ti
mo ṣe nigbati Jesebeli pa awọn woli Olu-
wa, bi mo ti pa ọgọrun enia mọ ninu awọn
woli Oluwa li aradọta ninu ihò-okuta, ti
mo si fi àkara pẹlu omi bọ́ wọn?
14 Nisisiyi, iwọ si wipe, Lọ sọ fun oluwa
rẹ pe, Wò o, Elijah mbẹ nihin! on o si
pa mi.
15 Elijah si wipe, Bi Oluwa awọn ọmọ-
ogun ti wà, niwaju ẹniti emi duro, nitõtọ,
emi o fi ara mi han fun u loni yi.
16 Bẽni Obadiah lọ lati pade Ahabu, o
si sọ fun u: Ahabu si lọ lati pade Elijah.
17 O si ṣe, bi Ahabu ti ri Elijah, Ahabu
si wi fun u pe, Iwọ li ẹniti nyọ Israeli li
ẹnu!
18 On si dahùn pe, Emi kò yọ Israeli li
ẹnu; bikoṣe iwọ ati ile baba rẹ, ninu eyiti
ẹnyin ti kọ̀ ofin Oluwa silẹ, ti iwọ si ti
ntọ̀ Baalimu lẹhin.
19 Nitorina, ranṣẹ nisisiyi, ki o si kó
gbogbo Israeli jọ sọdọ mi si oke Karmeli
ati awọn woli Baali adọtalenirinwo, ati
awọn woli ere-oriṣa irinwo, ti njẹun ni
tabili Jesebeli.
20 Bẽni Ahabu ranṣẹ si gbogbo awọn
ọmọ Israeli, o si kó awọn woli jọ si oke
Karmeli.
21 Elijah si tọ gbogbo awọn enia na wá,
o si wipe, Yio ti pẹ to ti ẹnyin o ma ṣiye-
meji? Bi Oluwa ba ni Ọlọrun, ẹ mã tọ̀ ọ
lẹhin: ṣugbọn bi Baali ba ni ẹ mã tọ̀ ọ
lẹhin! Awọn enia na kò si da a li ohùn
ọ̀rọ kan.
22 Elijah si wi fun awọn enia na pe,
Emi, ani emi nikanṣoṣo li o kù ni woli
Oluwa; ṣugbọn awọn woli Baali adọtaleni-
rinwọ ọkọnrin,
23 Nitorina jẹ ki nwọn ki o fun wa li
ẹgbọrọ akọ-malu meji; ki nwon ki o si yàn
ẹgbọrọ akọ-malu kan fun ara wọn, ki nwọn
ki o si ke e, ki nwọn ki o si tò o si ori igi,
ki nwọn ki o má ṣe fi iná si i: emi o si
tun ẹgbọrọ akọ-malu keji ṣe, emi o si tò o
sori igi, emi ki o si fi iná si i.
24 Ki ẹ si kepe orukọ awọn ọlọrun
nyin, emi o si kepè orukọ Oluwa: Ọlọrun
na ti o fi iná dahùn on na li Ọlọrun. Gbo-
gbo awọn enia na si dahùn, nwọn si wipe,
O wi i re.
25 Elijah si wi fun awọn woli Baali pe,
Ẹ yàn ẹgbọrọ akọ-malu kan fun ara nyin,
ki ẹ si tètekọ ṣe e: nitori ẹnyin pọ̀: ki ẹ
si kepè orukọ awọn ọlọrun nyin, ṣugbọn ẹ
máṣe fi inà si i,
26 Nwọn si mu ẹgbọrọ akọ-malu na ti a
fi fun wọn, nwọn si ṣe e, nwọn si kepè
orukọ Baali lati owurọ titi di ọ̀sangangan
wipe, Baali! da wa lohùn. Ṣugbọn kò si
ohùn, bẽni kò si idahùn. Nwọn si jò yi
pẹpẹ na ka, eyiti nwọn tẹ́.
27 O si ṣe, li ọ̀sangangan ni Elijah fi
wọn ṣe ẹlẹya o si wipe, Ẹ kigbe lohùn rara,
ọlọrun sa li on; bọya o nṣe àṣaro, tabi on
nlepa, tabi o re àjo, bọya o sùn, o yẹ ki a
ji i.
28 Nwọn si kigbe lohùn rara, nwọn si fi
ọbẹ ati ọ̀kọ ya ara wọn gẹgẹ bi iṣe wọn,
titi ẹ̀jẹ fi tu jade li ara wọn.
29 O si ṣe, nigbati ọjọ yẹ̀ atari, nwọn si
nfi were sọtẹlẹ titi di akoko irubọ aṣalẹ, kò
si ohùn, bẽni kò si idahùn, tabi ẹniti o kà
a si.
30 Njẹ Elijah wi fun gbogbo awọn enia

Digitized by Google

Ẹ sunmọ mi. Gbogbo awọn enia
ɜunmọ ọ. On si tun pẹpẹ Oluwa ti
ɔ lulẹ ṣe.
Elijah si mu okuta mejila, gẹgẹ bi
'a ọmọ Jakobu, ẹniti ọ̀rọ Oluwa tọ̀
ipe, Israeli li orukọ rẹ yio ma jẹ:
Okuta wọnyi li o fi tẹ́ pẹpẹ kan li
Oluwa, o si wà yàra yi pẹpẹ na ka,
gba iwọn oṣùwọn irugbin meji.
O si to igi na daradara, o si ke
ɔ akọ-malu na, o si tò o sori igi, o si
fi omi kún ikoko mẹrin, ki ẹ si tú u
bọ sisun ati sori igi na.
O si wipe, Ṣe e nigba keji. Nwọn
e nigba keji. O si wipe, Ṣe e nigba
Nwọn si ṣe e nigba kẹta.
Omi na si ṣàn yi pẹpẹ na ka, o si fi
:ún yàra na pẹlu.
O si ṣe, ni irubọ aṣalẹ, ni Elijah woli
ọ tòsi, o si wipe, Oluwa Ọlọrun Abra-
., Isaaki, ati Israeli, jẹ ki o di mimọ̀
ɔe, iwọ li Ọlọrun ni Israeli, emi si ni
ɜ rẹ, ati pe mo ṣe gbogbo nkan wọnyi
ọ̀rọ rẹ.
Gbọ́ ti emi, Oluwa, gbọ́ ti emi, ki
enia yi ki o le mọ̀ pe, Iwọ Oluwa li
ın, ati pe, Iwọ tún yi ọkàn wọn pada.
Nigbana ni iná Oluwa bọ́ silẹ, o si
ɟbọsisun na ati igi, ati okuta wọnnì,
:upẹ, o si lá omi ti mbẹ ninu yàra na.
Nigbati gbogbo awọn enia ri i, nwọn
ju wọn bolẹ: nwọn si wipe, Oluwa, on
ọrun; Oluwa, on li Ọlọrun!
Elijah si wi fun wọn pe, Ẹ mu awọn
Baali; máṣe jẹ ki ọkan ninu wọn ki o
Nwọn si mu wọn: Elijah si mu wọn
lẹ si odò Kiṣoni, o si pa wọn nibẹ.
Elijah si wi fun Ahabu pe, Goke lọ,
i o si mu; nitori iró ọ̀pọlọpọ ọ̀jò mbẹ.
! Bẹ̃ni Ahabu goke lọ lati jẹ ati lati
Elijah si gun ori oke Karmeli lọ; o
ɟriba o si fi oju rẹ̀ si agbedemeji ẽkun

3 O si wi fun ọmọ-ọdọ rẹ̀ pe, Goke lọ
ɜiyi, ki o si wò iha okun. On si goke
ɔ si wò, o si wipe, Kò si nkan. O si
e, Tun lọ nigba meje.
4 O si ṣe, ni igba keje, o si wipe, Ki-
i, awọsanma kekere kan dide lati inu
n, gẹgẹ bi ọwọ́ enia. On si wipe, Goke
wi fun Ahabu pe, Di kẹkẹ́ rẹ, ki o si
ɑlẹ, ki ọ̀jo ki o má ba da ọ duro.
5 O si ṣe, nigba diẹ si i, ọrun si ṣu fun
ɔsanma on iji, ọ̀jo pupọ si rọ̀. Ahabu
ɟun kẹkẹ́, o si lọ si Jesreeli.
.6 Ọwọ́ Oluwa si mbẹ lara Elijah: o si
di amure ẹ̀gbẹ rẹ̀, o si sare niwaju Ahabu
titi de Jesreeli.

ORI 19.

AHABU si sọ ohun gbogbo, ti Elijah ti
ṣe, fun Jesebeli, ati pẹlu bi o ti fi idà
pa gbogbo awọn woli.
2 Nigbana ni Jesebéli rán onṣẹ kan si
Elijah, wipe, Bẹ̃ni ki awọn òriṣa ki o ṣe si
mi ati jù bẹ̃ lọ pẹlu, bi emi kò ba ṣe ẹmi rẹ
dabi ọkan ninu wọn ni iwoyi ọla.
3 O si bẹ̀ru, o si dide, o si lọ fun ẹmi
rẹ̀, o si de Beerṣeba ti Juda, o si fi ọmọ-
ọdọ rẹ̀ silẹ nibẹ.
4 Ṣugbọn on tikararẹ̀ lọ ni irin ọjọ kan
si aginju, o si wá, o si joko labẹ igi juni-
peri kan, o si tọrọ fun ara rẹ̀ ki on ba le
kú; o si wipe, O to; nisisiyi, Oluwa, gba
ẹmi mi kuro nitori emi kò sàn jù awọn
baba mi lọ!
5 Bi o si ti dùbulẹ ti o si sùn labẹ igi
juniperi kan, si wò o, angeli fi ọwọ́ tọ́ ọ, o si
wi fun u pe, Dide, jẹun.
6 O si wò, si kiyesi i, àkara ti a din lori
ẹyin iná, ati orù-omi lẹba ori rẹ̀: o si jẹ, o
si mu, o si tun dùbulẹ.
7 Angeli Oluwa si tun pada wá lẹrinkeji,
o si fi ọwọ́ tọ́ ọ, o si wipe, Dide, jẹun; ni-
toriti ọ̀na na jìn fun ọ.
8 O si dide, o si jẹ, o mu, o si lọ li
agbara onjẹ yi li ogoji ọsan ati ogoji oru si
Horebu, oke Ọlọrun.
9 O si de ibẹ̀, si ibi ihò okuta, o si wọ̀
sibẹ, si kiyesi i, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ ọ wá, o si wi
fun u pe, Kini iwọ nṣe nihinyi, Elijah?
10 On si wipe, Ni jijowu emi ti njowu
fun Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun: ni-
toriti awọn ọmọ Israeli ti kọ̀ majẹmu rẹ
silẹ, nwọn ti wó awọn pẹpẹ rẹ lulẹ, nwọn
si ti fi idà pa awọn woli rẹ: ati emi, ani
emi nikanṣoṣo li o kù, nwọn si nwá ẹmi
mi lati gba a kuro.
11 O si wipe, Jade lọ, ki o si duro lori
oke niwaju Oluwa. Si kiyesi i, Oluwa
kọja, ìji nla ati lile si fà awọn oke nla ya,
o si fọ́ awọn apata tũtu niwaju Oluwa,
ṣugbọn Oluwa kò si ninu ìji na: ati lẹhin
ìji na, iṣẹlẹ; ṣugbọn Oluwa kò si ninu
iṣẹlẹ na.
12 Ati lẹhin iṣẹlẹ na, iná: ṣugbọn Olu-
wa kò si ninu iná na, ati lẹhin iná na,
ohùn kẹ́lẹ kekere.
13 O si ṣe, nigbati Elijah gbọ́, o si fi
agbáda rẹ̀ bo oju rẹ̀, o si jade lọ, o duro li
ẹnu iho okuta na. Si kiyesi i, ohùn kan
tọ̀ ọ wá wipe, Kini iwọ nṣe nihinyi Elijah?

Digitized by Google

14 On si wipe, Ni jijowu, emi ti njowu fun Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun: nitoriti awọn ọmọ Israeli ti kọ̀ majẹmu rẹ silẹ, nwọn si ti wó awọn pẹpẹ rẹ lulẹ, nwọn si ti fi idà pa awọn woli rẹ; ati emi, ani emi nikanṣoṣo li o kù; nwọn si nwá ẹmi mi lati gba a kuro.

15 Oluwa si wi fun u pe, Lọ, pada li ọ̀na rẹ, kọja li aginju si Damasku: nigbati iwọ ba de ibẹ, ki o si fi ororo yan Hasaeli li ọba lori Siria.

16 Ati Jehu, ọmọ Nimṣi ni iwọ o fi ororo yàn li ọba lori Israeli: ati Eliṣa, ọmọ Ṣafati, ara Abel-Mehola ni iwọ o fi ororo yàn ni woli ni ipò rẹ.

17 Yio si ṣe, ẹniti o ba sala kuro lọwọ idà Hasaeli ni Jehu yio pa, ati ẹniti o ba sala kuro lọwọ idà Jehu ni Eliṣa yio pa.

18 Ṣugbọn emi ti kù ọdẹgbarin enia silẹ fun ara mi ni Israeli, gbogbo ẽkun ti kò ti ikunlẹ fun Baali, ati gbogbo ẹnu ti kò iti fi ẹnu kò o li ẹnu.

19 Bẽni o pada kuro nibẹ, o si ri Eliṣa, ọmọ Ṣafati o nfi àjaga malu mejila tulẹ niwaju rẹ̀, ati on na pẹlu ikejila: Elijah si kọja tọ̀ ọ lọ, o si da agbáda rẹ̀ bò o.

20 O si fi awọn malu silẹ o si sare tọ̀ Elijah lẹhin o si wipe, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki emi lọ ifi ẹnu kò baba ati iya mi li ẹnu, nigbana ni emi o tọ̀ ọ lẹhin. O si wi fun u pe, Lọ, pada, nitori kini mo fi ṣe ọ?

21 O si pada lẹhin rẹ̀, o si mu àjaga malu kan, o si pa wọn, o si fi ohun-elo awọn malu na bọ̀ ẹran wọn, o si fi fun awọn enia, nwọn si jẹ. On si dide, o si tẹle Elijah lẹhin, o si ṣe iranṣẹ fun u.

## ORI 20.

BENHADADI, oba Siria si gbá gbogbo ogun rẹ̀ jọ: ọba mejilelọgbọn si mbẹ pẹlu rẹ̀ ati ẹṣin ati kẹkẹ́: o si gokè lọ, o si dóti Samaria, o ba a jagun.

2 O si rán awọn onṣẹ sinu ilu, sọdọ Ahabu, ọba Israeli, o si wi fun u pe, Bayi ni Benhadadi wi.

3 Fadaka rẹ ati wura rẹ ti emi ni; awọn aya rẹ pẹlu ati awọn ọmọ rẹ, ani awọn ti o dara jùlọ, temi ni nwọn.

4 Ọba Israeli si dahùn o si wipe, oluwa mi, ọba, gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ tirẹ li emi, ati ohun gbogbo ti mo ni.

5 Awọn onṣẹ si tun padà wá, nwọn si wipe, Bayi ni Benhadidi sọ wipe, Mo tilẹ ranṣẹ si ọ wipe, Ki iwọ ki o fi fadaka rẹ ati wura rẹ, ati awọn aya rẹ, ati awọn ọmọ rẹ le mi lọwọ;

6 Nigbati emi ba rán awọn iranṣẹ mi si ọ ni iwòyi ọla, nigbana ni nwọn o wá ile rẹ wò, ati ile awọn iranṣẹ rẹ; yio si ṣe, ohunkohun ti o ba dara loju rẹ, on ni nwọn o fi si ọwọ́ wọn, nwọn o si mu u lọ.

7 Nigbana ni ọba Israeli pè gbogbo awọn àgba ilu, o si wipe, Ẹ fiyèsi i, emi bẹ̀ nyin, ki ẹ si wò bi ọkọnrin yi ti nfẹ́ ẹ̀fẹ: nitoriti o ranṣẹ si mi fun awọn aya mi, ati fun awọn ọmọ mi, ati fun fadaka mi, ati fun wura mi, emi kò si fi dù u.

8 Ati gbogbo awọn àgba ati gbogbo awọn enia wi fun u pe, Máṣe fi eti si tirẹ̀, bẽni ki o máṣe gbà fun u.

9 Nitorina li o sọ fun awọn onṣẹ Benhadadi pe, Wi fun oluwa mi ọba pe, ohun gbogbo ti iwọ ranṣẹ fun, sọdọ iranṣẹ rẹ latetekọṣe li emi o ṣe: ṣugbọn nkan yi li emi kò le ṣe. Awọn onṣẹ na pada lọ, nwọn si tun mu èsi fun u wá.

10 Benhadadi si ranṣẹ si i, o si wipe, Ki awọn oriṣa ki o ṣe bẽ si mi, ati jù bẽ lọ pẹlu, bi ẽkuru Samaria yio to fun ikunwọ fun gbogbo enia ti ntẹle mi.

11 Ọba Israeli si dahùn, o si wipe, Wi fun u pe, Má jẹ ki ẹniti nhamọra, ki o halẹ bi ẹniti mbọ́ ọ silẹ,

12 O si ṣe, nigbati Benhadadi gbọ́ ọ̀rọ yi, bi o ti nmuti, on ati awọn ọba ninu agọ, li o sọ fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe, Ẹ tẹ́gun si ilu na.

13 Si kiyesi i, woli kan tọ̀ Ahabu, ọba Israeli wá, wipe, Bayi li Oluwa wi, Iwọ ri gbogbo ọ̀pọlọpọ yi? kiyesi i, emi o fi wọn le ọ lọwọ loni; iwọ o si mọ̀ pe, Emi li Oluwa.

14 Ahabu wipe, Nipa tani? On si wipe, Bayi li Oluwa wi, Nipa awọn ipẹrẹ̀ awọn ijoye igberiko. Nigbana li o wipe, Tani yio wé ogun na? On si dahùn pe: Iwọ.

15 Nigbana li o kà awọn ipẹrẹ̀ awọn ijoye igberiko, nwọn si jẹ igba o le mejilelọgbọn: lẹhin wọn li o si kà gbogbo awọn enia, ani gbogbo awọn ọmọ Israeli jẹ ẹdẹgbarin.

16 Nwọn si jade lọ li ọjọ-kanri. Ṣugbọn Benhadadi mu amupara ninu agọ, on, ati awọn ọba, awọn ọba mejilelọgbọn ti nràn a lọwọ.

17 Awọn ipẹrẹ̀ awọn ijoye igberiko tètekọ jade lọ: Benhadadi si ranṣẹ jade, nwọn si sọ fun u wipe, awọn ọkọnrin nti Samaria jade wá.

18 On si wipe, Bi nwọn ba bá ti alafia jade, ẹ mu wọn lãye; tabi bi ti ogun ni nwọn ba bá jade, ẹ mu wọn lãye.

Digitized by Google

19 Bẹ̃ni awọn ipẹrẹ̀ wọnyi ti awọn ijoye igberiko jade ti ilu wá, ati ogun ti o tẹle wọn.

20 Nwọn si pa, olukuluku ọkọnrin kọkan; awọn ara Siria sa; Israeli si lepa wọn: Benhadadi, ọba Siria si sala lori ẹṣin pẹlu awọn ẹlẹṣin.

21 Ọba Israeli si jade lọ, o si kọlu awọn ẹṣin ati kẹkẹ́, o pa awọn ara Siria li ọ̀pọlọpọ.

22 Woli na si wá sọdọ ọba Israeli, o si wi fun u pe, Lọ, mu ara rẹ giri, ki o si mọ̀, ki o si wò ohun ti iwọ nṣe: nitori li amọdun, ọba Siria yio goke tọ̀ ọ wá.

23 Awọn iranṣẹ ọba Siria si wi fun u pe, ọlọrun wọn, ọlọrun oke ni; nitorina ni nwọn ṣe li agbara jù wa lọ; ṣugbọn jẹ ki a ba wọn jà ni pẹtẹlẹ, awa o si li agbara jù wọn lọ nitõtọ.

24 Nkan yi ni ki o si ṣe, mu awọn ọba kuro, olukuluku kuro ni ipò rẹ̀, ki o si fi olori-ogun si ipò wọn.

25 Ki o si kà iye ogun fun ara rẹ gẹgẹ bi ogun ti o ti fọ́, ẹṣin fun ẹṣin, ati kẹkẹ́ fun kẹkẹ́: awa o si ba wọn jà ni pẹtẹlẹ, nitõtọ awa o li agbara jù wọn lọ. O si fi eti si ohùn wọn, o si ṣe bẹ̃.

26 O si ṣe li amọdun, ni Benhadadi kà iye awọn ara Siria, nwọn si goke lọ si Afeki, lati bá Israeli jagun.

27 A si ka iye awọn ọmọ Israeli, nwọn si pese onjẹ, nwọn si lọ ipade wọn: awọn ọmọ Israeli si dó niwaju wọn gẹgẹ bi agbo ọmọ ewurẹ kekere meji: ṣugbọn awọn ara Siria kún ilẹ na.

28 Enia Ọlọrun kan si wá, o si sọ fun ọba Israeli, o si wipe, Bayi li Oluwa wi, Nitoriti awọn ara Siria wipe, Oluwa, Ọlọrun oke ni, ṣugbon on kì iṣe Ọlọrun afonifoji, nitorina emi o fi gbogbo ọ̀pọlọpọ enia yi le ọ lọwọ́, ẹnyin o si mọ̀ pe, Emi li Oluwa.

29 Nwọn si dó, ekini tì ekeji ni ijọ meje. O si ṣe, li ọjọ keje, nwọn padegun, awọn ọmọ Israeli si pa ọkẹ marun ẹlẹsẹ̀ ninu awọn ara Siria li ọjọ kan.

30 Ṣugbọn awọn iyokù salọ si Afeki, sinu ilu; odi si wolu ẹgbamẹtala-le-ẹgbẹrun ninu awọn enia ti o kù. Benhadadi si sa lọ, o si wá sinu ilu lati iyẹwu de iyẹwu.

31 Awọn iranṣẹ rẹ̀ si wi fun u pe, Kiyesi i, nisisiyi, awa ti gbọ́ pe, awọn ọba ile Israeli, alãnu ọba ni nwọn: mo bẹ ọ, jẹ ki awa ki o fi aṣọ-ọ̀fọ si ẹgbẹ wa, ati ijará yi ori wa ka, ki a si jade tọ̀ ọba Israeli lọ: bọya on o gba ẹmi rẹ là.

32 Bẹ̃ni nwọn di aṣọ ọ̀fọ mọ ẹgbẹ wọn, nwọn si fi ijara yi ori wọn ka, nwọn si tọ̀ ọba Israeli wá, nwọn si wipe, Benhadadi, iranṣẹ rẹ, wipe, Emi bẹ ọ, jẹ ki ẹmi mi ki o yè. On si wipe, O mbẹ lãye sibẹ? arakọnrin mi li on iṣe.

33 Awọn ọkọnrin na si ṣe akiyesi i gidigidi, nwọn si yara gbá ohun ti o ti ọdọ rẹ̀ wá mu: nwọn si wipe, Benhadadi arakọnrin rẹ! Nigbana li o wipe, Ẹ lọ mu u wá. Nigbana ni Benhadadi jade tọ̀ ọ wá; o si mu u goke wá sinu kẹkẹ́.

34 On si wi fun u pe, Awọn ilu ti baba mi gbà lọwọ baba rẹ, emi o mu wọn pada: iwọ o si là ọ̀na fun ara rẹ ni Damasku, bi baba mi ti ṣe ni Samaria. Nigbana ni Ahabu wipe, Emi o rán ọ lọ pẹlu majẹmu yi. Bẹ̃ li o ba a dá majẹmu, o si rán a lọ.

35 Ọkọnrin kan ninu awọn ọmọ awọn woli si wi fun ẹnikeji rẹ̀ nipa ọ̀rọ Oluwa pe, Jõ, lù mi. Ọkọnrin na si kọ̀ lati lù u.

36 Nigbana li o wi pe, Nitoriti iwọ kò gbà ohùn Oluwa gbọ́, kiyesi i, bi iwọ ba ti ọdọ mi kuro, kiniun yio pa ọ. Bi o si ti jade lọ lọdọ rẹ̀, kiniun kan ri i o si pa a.

37 Nigbana li o si ri ọkọnrin miran, o si wipe, Jõ, lù mi. Ọkọnrin na si lù u, ni lilu ti o lù u, o pa a lara.

38 Woli na si lọ, o si duro de ọba loju ọ̀na, o pa ara rẹ̀ da, ni fifi ẽru ba oju.

39 Bi ọba si ti nkọja lọ, o ke si ọba o si wipe, iranṣẹ rẹ jade wọ arin ogun lọ; si kiyesi i, ọkọnrin kan yà sapakan, o si mu ọkọnrin kan fun mi wá o si wipe: Pa ọkọnrin yi mọ; bi a ba fẹ ẹ kù, nigbana ni ẹmi rẹ yio lọ fun ẹmi rẹ̀, bi bẹ̃ kọ, iwọ o san talenti fadaka kan.

40 Bi iranṣẹ rẹ si ti ni iṣe nihin ati lọhun, a fẹ ẹ kù. Ọba Israeli si wi fun u pe, Bẹ̃ni idajọ rẹ yio ri: iwọ tikararẹ ti dá a.

41 O si yara, o si mu ẽru kuro li oju rẹ̀; ọba Israeli si ri i daju pe, ọkan ninu awọn woli ni on iṣe.

42 O si wi fun u pe, Bayi li Oluwa wi, nitoriti iwọ jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ, ọkọnrin ti emi ti yàn si iparun patapata, ẹmi rẹ yio lọ fun ẹmi rẹ̀, ati enia rẹ fun enia rẹ̀.

43 Ọba Israeli si lọ si ile rẹ̀, o wugbọ, inu rẹ̀ si bajẹ, o si wá si Samaria.

## ORI 21.

O SI ṣe lẹhín nkan wọnyi, Naboti, ara Jesreeli, ni ọgba-ajara ti o wà ni Jesreeli, ti o sunmọ ãfin Ahabu, ọba Samaria girigiri.

Digitized by Google

2 Ahabu si ba Naboti sọ wipe, Fun mi
ni ọgba-ajara rẹ, ki emi ki o fi ṣe ọgba-
ewebẹ̀, nitori ti o sunmọ ile mi: emi o si
fun ọ li ọgba-ajara ti o san jù u lọ dipò rẹ̀;
bi o ba si dara li oju rẹ, emi o fi iye-owo
rẹ̀ fun ọ.
3 Naboti si wi fun Ahabu pe, Oluwa
má jẹ ki emi fi ogún awọn baba mi fun ọ.
4 Ahabu si wá si ile rẹ̀, o wugbọ, inu
rẹ̀ si bajẹ nitori ọ̀rọ ti Naboti, ara Jesreeli,
sọ fun u: nitoriti on ti wipe, emi kì o fun
ọ ni ogún awọn baba mi. On si dubulẹ
lori akete rẹ̀, o si yi oju rẹ̀ padà, kò si fẹ
ijẹun.
5 Jesebeli, aya rẹ̀ si tọ̀ ọ wá o si wi
fun u pe, Ëṣe ti inu rẹ fi bajẹ́ ti iwọ kò
fi jẹun?
6 O si wi fun u pe, Nitoriti mo ba Na-
boti, ara Jesreeli sọ, mo si wi fun u pe,
Fun mi ni ọgba-àjara rẹ fun owo; tabi bi
o ba wù ọ, emi o fun ọ ni ọgba-àjara miran
ni ipò rẹ̀: o si dahùn wipe, Emi kì o fun
ọ ni ọgba-àjara mi.
7 Jesebeli, aya rẹ̀ si wi fun u pe, iwọ
kò ha jọba lori Israeli nisisiyi? Dide,
jẹun, ki o si jẹ ki inu rẹ ki o dùn! emi o
fun ọ ni ọgba-àjara Nãboti ara Jesreeli.
8 Bẹ̃ni o kọwe li orukọ Ahabu, o si fi
èdidi rẹ̀ di i, o si fi iwe na ṣọwọ sọdọ awọn
àgbagba ati awọn ọlọla ti mbẹ ni ilu rẹ̀,
ti o si mba Naboti gbe.
9 O si kọ sinu iwe na pe, Ẹ kede àwẹ,
ki ẹ si fi Naboti si ipò ọla lãrin awọn
enia:
10 Ki ẹ fi enia meji, ẹni buburu, siwaju
rẹ̀ lati jẹri pa a, wipe, Iwọ bu Ọlọrun ati
ọba. Ẹ mu u jade, ki ẹ si sọ li okuta ki
o le kù.
11 Awọn ọkọnrin ilu rẹ̀, ati awọn à-
gbagba, ati-awọn ọlọla ti nwọn iṣo ara-ilu
rẹ̀, ṣe bi Jesebeli ti ranṣẹ si wọn, gẹgẹ bi
a ti kọ ọ sinu iwe ti o ti fi ranṣẹ si wọn.
12 Nwọn si kede-àwẹ, nwọn si fi Naboti
si ipò ọla lãrin awọn enia.
13 Ọkọnrin meji si de, awọn ẹni buburu,
nwọn si joko niwaju rẹ̀: awọn ọkọnrin
buburu si jẹri pa a, ani si Naboti, niwaju
awọn enia wipe: Naboti bu Ọlọrun ati
ọba. Nigbana ni nwọn mu u jade kuro
ni ilu, nwọn si sọ ọ li okuta, o si kú.
14 Nigbana ni nwọn ranṣe si Jesebeli
wipe, A sọ Naboti li okuta, o si kú.
15 O si ṣe, nigbati Jesebeli gbọ́ pe, a sọ
Naboti li okuta, o si kú, Jesebeli sọ fun
Ahabu pe, Dide! ki o si jogun ọgba-ajara
Naboti, ara Jesreeli, ti o kọ̀ lati fi fun
ọ fun owo; nitori Naboti kò si lãye ṣugbọn
o kú.
16 O si ṣe, nigbati Ahabu gbọ́ pe,
Naboti kú, ni Ahabu dide lati sọkalẹ
lọ si ọgbo-ajara Naboti, ara Jesreeli lati
jogun rẹ̀.
17 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ Elijah, ara Tiṣbi wá
wipe,
18 Dide, sọkalẹ, lọ ipade Ahabu, ọba
Israeli, ti o wà ni Samaria: wò o, o wà
ni ọgba-ajara Naboti, nibiti o sọkalẹ lọ
lati jogun rẹ̀.
19 Iwọ o si wi fun u pe, Bayi li Oluwa
wi: Iwọ ti pa, iwọ si ti jogun pẹlu? Iwọ
o si wi fun u pe, Bayi li Oluwa wi pe, Ni
ibi ti ajá gbe lá ẹ̀jẹ Naboti, ni awọn ajá
yio lá ẹ̀jẹ rẹ, ani tirẹ.
20 Ahabu si wi fun Elijah pe, Iwọ ri
mi, Iwọ ọta mi? O si dahùn wipe, Emi
ri ọ; nitoriti iwọ ti tà ara rẹ lati ṣiṣẹ
buburu niwaju Oluwa.
21 Kiyesi i, Emi o mu ibi wá si ori rẹ,
emi o si mu iran rẹ kuro, emi o si ke kuro
lọdọ Ahabu, gbogbo ọmọde ọkọnrin, ati
ọmọ-ọdọ, ati omnira ni Israeli.
22 Emi o si ṣe ile rẹ bi ilẹ Jeroboamu,
ọmọ Nebati, ati bi ile Baaṣa, ọmọ Ahijah,
nitori imunibinu ti iwọ ti mu mi binu, ti
iwọ si mu ki Israeli ki o dẹṣẹ,
23 Ati niti Jesebeli pẹlu Oluwa sọ wipe,
Awọn ajá yio jẹ Jesebeli ninu yàra Jesreeli.
24 Ẹni Ahabu ti o kú ni ilu, ni awọn
ajá o jẹ: ati ẹniti o kú ni igbẹ ni awọn
ẹiyẹ oju-ọrun o jẹ.
25 Ṣugbọn kò si ẹnikan bi Ahabu ti o
tà ara rẹ̀ lati ṣiṣẹ buburu niwaju Oluwa,
ẹniti Jesebeli aya rẹ̀ ntì.
26 O si ṣe ohun irira gidigidi ni titọ̀
oriṣa lẹhin, gẹgẹ bi gbogbo ohun ti awọn
ara Amori ti ṣe, ti Oluwa ti le jade niwaju
awọn ọmọ Israeli.
27 O si ṣe, nigbati Ahabu gbọ́ ọ̀rọ
wọnyi, o si fa aṣọ rẹ̀ ya, o si fi aṣọ ọ̀fọ si
ara rẹ̀, o si gbàwẹ, o si dubulẹ ninu aṣọ
ọ̀fọ, o si nlọ jẹ́.
28 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ Elijah, ara Tiṣbi wá
wipe,
29 Iwọ ri bi Ahabu ti rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ
niwaju mi? Nitori ti o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ ni-
waju mi, emi kì yio mu ibi na wá li ọjọ
rẹ̀: li ọjọ ọmọ rẹ̀ li emi o mu ibi na wá
sori ile rẹ̀.

## ORI 22.

ỌDUN mẹta si rekọja laisi ogun lãrin
Siria ati lãrin Israeli.

2 O si ṣe li ọdun kẹta, Jehoṣafati, ọba
Juda sọkalẹ tọ ọba Israeli wá.
3 Ọba Israeli si wi fun awọn iranṣẹ rẹ̀
pe, Ẹnyin ha mọ̀ pe, tiwa ni Ramoti-
Gileadi, awa si dakẹ, a kò si gbà a kuro
lọwọ ọba Siria?
4 O si wi fun Jehoṣafati pe, Iwọ o ha
bá mi lọ si ogun Ramoti-Gileadi bi? Je-
hoṣafati si wi fun ọba Israeli pe, Emi bi
iwọ, enia mi bi enia rẹ, ẹṣin mi bi ẹṣin rẹ.
5 Jehoṣafati si wi fun ọba Israeli pe, Mo
bẹ̀ ọ, bère ọ̀rọ Oluwa li oni yi.
6 Nigbana ni ọba Israeli kó awọn woli
jọ, bi irinwọ ọkọnrin, o si wi fun wọn pe,
Ki emi ki o ha lọ si Ramoti-Gileadi lọ
ijagun, tabi ki emi ki o jọwọ rẹ̀? Nwọn
si wipe, Goke lọ: nitoriti Oluwa yio fi i
le ọba lọwọ.
7 Jehoṣafati si wipe, Kò si woli Oluwa
kan nihin pẹlu, ti awa iba bère lọwọ rẹ̀?
8 Ọba Israeli si wi fun Jehoṣafati pe,
Ọkọnrin kan Mikaiah, ọmọ Imla, mbẹ
sibẹ, lọdọ ẹniti awa iba bère lọwọ Oluwa:
ṣugbọn emi korira rẹ̀, nitori kì isọ asọtẹlẹ
ire si mi, bikoṣe ibi. Jehoṣafati si wipe,
Ki ọba má sọ bẹ̃.
9 Ọba Israeli si pè iwẹfa kan, o si wipe,
Mu ki Mikaiah, ọmọ Imla, ki o yara wá.
10 Ọba Israeli ati Jehoṣafati, ọba Juda
joko olukulùku lori itẹ́ rẹ̀, nwọn wọ̀ aṣọ
igunwa wọn ni ita ẹnu-bode Samaria,
gbogbo awọn woli na si nsọtẹlẹ niwaju wọn.
11 Sedekiah, ọmọ Kenaana si ṣe iwo irin
fun ara rẹ̀, o si wipe: Bayi li Oluwa wi,
Wọnyi ni iwọ o fi kàn ara Siria titi iwọ
o fi run wọn.
12 Gbogbo awọn woli si nsọtẹlẹ bẹ̃ wipe:
Goke lọ si Ramoti-Gileadi, ki o si ṣe rere:
nitoriti Oluwa yio fi i le ọba lọwọ.
13 Onṣẹ ti o lọ ipè Mikaiah wi fun u
pe, Kiyesi i nisisiyi, ẹnu kanna ni ọ̀rọ
awọn woli fi jẹ rerẹ fun ọba: emi bẹ̀ ọ,
jẹ ki ọ̀rọ rẹ ki o dabi ọ̀rọ ọkan ninu wọn,
ki o si sọ rere.
14 Mikaiah si wipe, Bi Oluwa ti wà,
ohun ti Oluwa ba sọ fun mi li emi o sọ.
15 Bẹ̃ni o de ọdọ ọba. Ọba si wi fun
u pe, Mikaiah, ki awa o ha lọ si Ramoti-
Gileadi lọ ijagun, tabi ki a jọwọ rẹ̀? O
si da a lohùn pe, Lọ, ki o si ṣe rere:
nitori Oluwa yio fi i le ọba lọwọ.
16 Ọba si wi fun u pẹ, Igba melo li emi
o fi ọ bu pe, ki iwọ ki o máṣe sọ ohun kan
fun mi bikoṣe otitọ li orukọ Oluwa?
17 On si wipe, Mo ri gbogbo Israeli
tukakiri lori awọn oke bi agutan ti kò
ni oluṣọ: Oluwa si wipe: Awọn wọnyi
kò ni oluwa, jẹ ki nwọn ki o pada oluku-
luku si ile rẹ̀ li alafia.
18 Ọba Israeli si wi fun Jehoṣafati pe,
Emi kò sọ fun ọ, pe on kì o fọ̀ ire si mi,
bikoṣe ibi?
19 On si wipe, Nitorini, iwọ gbọ́ ọ̀rọ
Oluwa: Mo ri Oluwa joko lori itẹ́ rẹ̀, ati
gbogbo ogun-ọrun duro li apa ọtun ati li
apa òsi rẹ̀.
20 Oluwa si wipe, Tani yio tàn Ahabu,
ki o le goke lọ, ki o si le ṣubu ni Ramoti-
Gileadi? Ẹnikan si wi bayi, ẹlomiran si
sọ miran.
21 Ẹmi kan si jade wá, o si duro niwaju
Oluwa, o si wipe, Emi o tàn a.
22 Oluwa si wi fun u pe, Bawo? O si
wipe, Emi o jade lọ, emi o si di ẹmi-eke li
ẹnu gbogbo awọn woli rẹ̀. On si wipe,
Iwọ o tàn a, iwọ o si bori pẹlu: jade lọ, ki
o si ṣe bẹ̃.
23 Njẹ nisisiyi, kiyesi i, Oluwa ti fi
ẹmi-eke si ẹnu gbogbo awọn woli rẹ wọnyi,
Oluwa si ti sọ ibi si ọ.
24 Nigbana ni Sedekiah, ọmọ Kenaana
sunmọ ọ, o si lu Mikaiah li ẹ̀rẹkẹ, o si
wipe, Ọna wo li ẹmi Oluwa gbà lọ kuro
lọdọ mi lati ba ọ sọ̀rọ?
25 Mikaiah si wipe, Kiyesi i, iwọ o ri i
li ọjọ na, nigbati iwọ o lọ lati inu iyẹwu de
iyẹwu lati fi ara rẹ pamọ.
26 Ọba Israeli si wipe, Mu Mikaiah, ki
ẹ si mu u pada sọdọ Amoni, olori ilu, ati
sọdọ Joasi, ọmọ ọba:
27 Ki ẹ si wipe, Bayi li ọba wi: Ẹ fi
eleyi sinu tubu, ki ẹ si fi onjẹ ipọnju ati
omi ipọnju bọ́ ọ, titi emi o fi pada bọ̀ li
alafia.
28 Mikaiah si wipe, Ni pipada bi iwọ ba
pada bọ̀ li alafia, njẹ Oluwa kò ti ipa mi
sọ̀rọ. O si wipe, Ẹ gbọ́, ẹnyin enia gbo-
gbo!
29 Bẹ̃ni ọba Israeli ati Jehoṣafati, ọba
Juda, goke lọ si Ramoti-Gileadi.
30 Ọba Israeli si wi fun Jehoṣafati pe,
Emi o pa aṣọ dà, emi o si lọ si oju ija;
ṣugbọn iwọ gbé aṣọ igunwà rẹ wọ̀. Ọba
Israeli si pa aṣọ dà, o si lọ si oju ijà.
31 Ṣugbọn ọba Siria paṣẹ fun awọn olori-
kẹkẹ́ rẹ̀, mejilelọgbọn, ti o ni aṣẹ lori kẹkẹ́
rẹ̀ wipe, Máṣe ba ẹni-kekere tabi ẹni-nla
jà, bikoṣe ọba Israeli nikan.
32 O si ṣe, bi awọn olori-kẹkẹ́ ti ri Je-
hoṣafati, nwọn si wipe, ọba Israeli li eyi.
Nwọn si yà sapakan lati ba a jà: Jehoṣa-
fati si kigbe.

Digitized by Google

33 O si ṣe, nigbati awọn olori kẹkẹ́ woye
pe, kì iṣe ọba Israeli li eyi, nwọn si pada
kuro lẹhin rẹ̀.
34 Ọkọnrin kan si fà ọrun rẹ̀ laipete, o
si ta ọba Israeli lãrin ipade ẹwu-irin ; nito-
rina li o ṣe wi fun olutọju-kẹkẹ́ rẹ̀ pe, Yi
ọwọ́ rẹ dà, ki o si mu mi jade kuro ninu
ogun ; nitoriti emi gbọgbẹ.
35 Ogun na si le li ọjọ na : a si dá ọba
duro ninu kẹkẹ́ kọju si awọn ara Siria, o si
kú li aṣalẹ, ẹ̀jẹ si ṣàn jade lati inu ọgbẹ na
si ãrin kẹkẹ́ na.
36 A si kede la ibudo já li akokò iwọ̀
õrun wipe, Olukuluku si ilu rẹ̀, ati oluku-
luku si ilẹ rẹ̀.
37 Bẹ̃ni ọba kú, a si gbe e wá si Samaria;
nwọn si sin ọba ni Samaria.
38 Ẹnikan si wẹ kẹkẹ́ na ni adagun Sa-
maria, awọn ajá si la ẹ̀jẹ rẹ̀ ; awọn àgbere
si wẹ ara wọn ninu rẹ̀ gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa ti
o sọ,
39 Ati iyokù iṣe Ahabu, ati gbogbo eyi
ti o ṣe, ati ile ehin-erin ti o kọ́, ati gbogbo
ilu ti o tẹ̀do, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
ọjọ awọn ọba Israeli?
40 Ahabu si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀ ;
Ahasiah, ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
41 Jehoṣafati, ọmọ Asa, si bẹ̀rẹ si ijọba
lori Juda li ọdun kẹrin Ahabu, ọba Israeli.
42 Jehoṣafati si to ẹni ọdun marundilo-
goji nigbati o bẹ̀re si ijọba ; o si jọba ọdun
mẹ̃dọgbọn ni Jerusalẹmu. Orukọ iya rẹ̀ ni
Asuba ọmọbirin Ṣilhi.
43 O si rin ni gbogbo ọ̀na Asa baba rẹ̀ ;
kò yipada kuro ninu rẹ̀, o nṣe eyiti o tọ li
oju Oluwa : kiki a kò mu awọn ibi giga
kuro ; awọn enia si nrú ẹbọ, nwọn si nsun
turari sibẹ̀ ni ibi giga wọnni.
44 Jehoṣafati si wà li alafia pẹlu ọba
Israeli.
45 Ati iyokù iṣe Jehoṣafati ati iṣe agbara
rẹ̀ ti o ṣe, ati bi o ti jagun si, a kò ha kọ
wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Juda ?
46 Iyokù awọn ti nhuwà panṣaga ti o
kù li ọjọ Asa baba rẹ̀, li o parun kuro ni
ilẹ na.
47 Nigbana kò si ọba ni Edomu : adèlé
kan li ọba.
48 Jehoṣafati kàn ọkọ̀ Tarṣiṣi lati lọ si
Ofiri fun wura ; ṣugbọn nwọn kò lọ : nito-
ri awọn ọkọ̀ na fọ́ ni Esion-Geberi.
49 Nigbana ni Ahasiah, ọmọ Ahabu, wi
fun Jehoṣafati pe, Jẹ ki awọn iranṣẹ mi ba
awọn iranṣẹ rẹ lọ ninu ọkọ̀. Ṣugbọn Je-
hoṣafati kọ̀.
50 Jehoṣafati si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀,
a si sin i pẹlu awọn baba rẹ̀ ni ilu Dafidi,
baba rẹ̀ : Jehoramu, ọmọ rẹ̀, si jọba ni ipò
rẹ̀.
51 Ahasiah, ọmọ Ahabu, bẹ̀rẹ si ijọba
lori Israeli ni Samaria li ọdun kẹtadilogun
Jehoṣafati, ọba Juda, o si jọba li ọdun meji
lori Israeli.
52 O si ṣe ibi niwaju Oluwa, o si rìn li
ọ̀na baba rẹ̀, ati li ọ̀na iya rẹ̀, ati li ọ̀na
Jeroboamu, ọmọ Nebati, ti o mu Israeli
dẹṣẹ :
53 Nitoriti o sin Baali, o si mbọ ọ, o si
mu Oluwa, Ọlọrun Israeli binu, gẹgẹ bi
gbogbo eyiti baba rẹ̀ ti ṣe.

---

IWE EKEJI

# AWỌN ỌBA.

## ORI 1.

NIGBANA ni Moabu ṣọ̀tẹ si Israeli lẹhin
ikú Ahabu.
2 Ahasiah si ṣubu lãrin fèrese ọlọnà kan
ni iyara òke rẹ̀ ti o wà ni Samaria, o si ṣài-
san : o si rán awọn onṣẹ o si wi fun wọn pe,
Ẹ lọ, ẹ bère lọwọ Baalsebubu, oriṣa Ekroni,
bi emi o là ninu aisan yi.
3 Ṣugbọn angeli Oluwa wi fun Elijah,
ara Tiṣbi pe, Dide, gòke lọ ipade awọn onṣẹ
ọba Samaria, ki o si wi fun wọn pe, Kò ṣe
pe nitoriti kò si Ọlọrun ni Israeli, ni ẹnyin
fi nlọ ibère lọwọ Baalsebubu oriṣa Ekroni ?
4 Njẹ nitorina bayi li Oluwa wi, Iwọ kì
o sọkalẹ kuro lori akete nì lori eyiti iwọ ti
gùn, ṣugbọn kikú ni iwọ o kú. Elijah si
lọ kuro.

Digitized by Google

5 Nigbati awọn onṣẹ si pada si ọdọ rẹ̀, o
wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi pada sẹhin?
6 Nwọn si wi fun u pe, Ọkọnrin kan li o
gòke lati pade wa, o si wi fun wa pe, Ẹ lọ,
ẹ pada tọ̀ ọba ti o rán nyin, ki ẹ si wi fun
u pe, Bayi li Oluwa wi, kò ṣepe nitoriti kò
si Ọlọrun ni Israeli, ni iwọ fi ranṣẹ lọ
ibère lọwọ Baalsebubu oriṣa Ekroni? nito-
rina, iwọ kì o sọ̀kalẹ 'kuro lori akete nì ti
iwọ ti gùn, ṣugbọn kikú ni iwọ o kú.
7 On si wi fun wọn pe, Iru ọkọnrin wo
li ẹniti o gòke lati pade nyin, ti o si sọ̀rọ
wọnyi fun nyin?
8 Nwọn si da a li ohùn pe, Ọkọnrin oni-
run li ara ni; o si dì àmure awọ mọ́ ẹgbẹ́
rẹ̀. On si wipe, Elijah ara Tiṣbi ni.
9 Nigbana ni ọba rán olori-ogun ãdọta
kan pẹlu ãdọta rẹ̀. O si gòke tọ̀ ọ lọ: si
kiyesi i, o joko lori òke kan. On si wi fun
u pe, Iwọ enia Ọlọrun, ọba wipe, Sọ̀kalẹ.
10 Elijah si dahùn, o si wi fun olori-
ogun ãdọta na pe, Bi emi ba ṣe enia Ọlọrun,
jẹ ki iná ki o sọ̀kalẹ lati ọrun wá, ki o run ọ
ati ãdọta rẹ. Iná si sọ̀kalẹ ti ọrun wá, o
si run u ati ãdọta rẹ̀.
11 On si tun rán olori-ogun ãdọta miran
pẹlu ãdọta rẹ̀. On si dahùn o si wi fun u
pe, Iwọ enia Ọlọrun, Bayi li ọba wi, yara
sọ̀kalẹ.
12 Elijah si dahùn, o si wi fun wọn pe,
Bi emi ba ṣe enia Ọlọrun, jẹ ki iná ki o
sọ̀kalẹ lati ọrun wá, ki o si run ọ ati ãdọta
rẹ. Iná Ọlọrun si sọ̀kalẹ lati ọrun wá, o si
run u ati ãdọta rẹ̀.
13 O si tun rán olori-ogun ãdọta ẹkẹta
pẹlu ãdọta rẹ̀. Olori-ogun ãdọta kẹta si
gòke, o si wá, o si wolẹ lori ẽkún rẹ̀ niwaju
Elijah, o si bẹ̀ ẹ, o si wi fun u pe, Iwọ,
enia Ọlọrun, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki ẹmi mi ati ẹmi
awọn ãdọta ọmọ-ọdọ rẹ wọnyi, ki o ṣọwọn
li oju rẹ.
14 Kiyesi i, iná sọ̀kalẹ lati ọrun wá, o si
run olori-ogun meji arãdọta iṣaju pẹlu ara-
dọta wọn: njẹ nisisiyi, jẹ ki ẹmi mi ki o
ṣọwọn li oju rẹ.
15 Angeli Oluwa si wi fun Elijah pe, Ba
a sọ̀kalẹ lọ: máṣe bẹ̀ru rẹ̀. On si dide, o
si ba a sọ̀kalẹ lọ sọdọ ọba.
16 On si wi fun u pe, Bayi li Oluwa wi,
nitoriti iwọ ran onṣẹ lọ ibère lọwọ Baalse-
bubu oriṣa Ekroni, kò ṣepe nitoriti kò si
Ọlọrun ni Israeli lati bère ọ̀rọ rẹ̀? nitorina
iwọ kì o sọ̀kalẹ kuro lori akete nì ti iwọ ti
gùn, ṣugbọn kikú ni iwọ o kú;
17 Bẹ̃ni o kú gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwá ti Eli-
jah ti sọ. Jehoramu si jọba ni ipò rẹ̀, li
ọdun keji Jehoramu ọmọ Jehoṣafati, ọba
Juda, nitoriti kò ni ọmọkọnrin.
18 Ati iyokù iṣe Ahasiah ti o ṣe, a kò
ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba
Israeli.

## ORI 2.

O SI ṣe, nigbati Oluwa nfẹ lati fi ãjà gbé
Elijah lọ si òke ọrun, ni Elijah ati
Eliṣa lọ kuro ni Gilgali.
2 Elijah si wi fun Eliṣa pe, Emi bẹ̀ ọ,
joko nihinyi; nitoriti Oluwa rán mi si
Beteli. Eliṣa si wi fun u pe, Bi Oluwa ti
mbẹ, ati bi ẹmi rẹ ti mbẹ, emi kì o fi ọ silẹ.
Bẹ̃ni nwọn sọ̀kalẹ lọ si Beteli.
3 Awọn ọmọ awọn woli ti mbẹ ni Beteli
jade tọ̀ Eliṣa wá, nwọn si wi fun u pe, Iwọ
ha mọ̀ pe Oluwa yio mu oluwa rẹ lọ kuro
li ori rẹ loni? On si wipe, Bẹ̃ni, emi mọ̀,
ẹ pa ẹnu nyin mọ́.
4 Elijah si wi fun u pe, Eliṣa, emi bẹ̀ ọ,
joko nihinyi; nitori ti Oluwa rán mi si
Jeriko. On si wipe, Bi Oluwa ti mbẹ, ati
bi ẹmi rẹ ti mbẹ, emi kì o fi ọ silẹ. Bẹ̃ni
nwọn de Jeriko.
5 Awọn ọmọ awọn wọli ti mbẹ ni Jeriko
tọ̀ Eliṣa wá, nwọn si wi fun u pe, Iwọ ha
mọ̀ pe Oluwa yio mu oluwa rẹ lọ kuro li
ori rẹ loni? On si dahùn wipe, Bẹ̃ni, emi
mọ̀, ẹ pa ẹnu nyin mọ́.
6 Elijah si wi fun u pe, Emi bẹ̀ ọ, joko
nihinyi; nitoriti Oluwa rán mi si Jordani.
On si wipe, Bi Oluwa ti mbẹ, ati bi ẹmi rẹ
ti mbẹ, emi kì o fi ọ silẹ. Awọn mejeji si
jùmọ nlọ.
7 Adọta ọkọnrin ninu awọn ọmọ awọn
woli si lọ nwọn si duro lati wò lòkere rére:
awọn mejeji si duro li ẹba Jordani.
8 Elijah si mu agbáda rẹ̀, o si lọ́ ọ lù, o
si lù omi na, o si pin wọn ni iyà sihin ati
sọhun, bẹ̃ni awọn mejeji si kọja ni ilẹ
gbigbẹ.
9 O si ṣe, nigbati nwọn kọja tan, ni
Elijah wi fun Eliṣa pe, Bère ohun ti emi o
ṣe fun ọ, ki a to gbà mi kuro lọwọ rẹ.
Eliṣa si wipe, Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki iṣẹ́po meji
ẹmi rẹ ki o bà le mi.
10 On si wipe, Iwọ bère ohun ti o ṣoro:
ṣugbọn, bi iwọ ba ri mi nigbati a ba gbà
mi kuro lọdọ rẹ, yio ri bẹ̃ fun ọ; ṣugbọn
bi bẹ̃kọ, kì yio ri bẹ̃.
11 O si ṣe, bi nwọn ti nlọ, ti nwọn nsọ̀-
rọ, si kiyesi i, kẹkẹ́ iná ati ẹṣin iná si là
ãrin awọn mejeji; Elijah si ba ãjà gòke re
ọrun.
12 Eliṣa si ri i, o si kigbe pe, Baba mi,

Digitized by Google

baba mi! kẹkẹ́ Israeli, ati awọn ẹlẹṣin rẹ̀.
On kò si ri i mọ: o si di aṣọ ara rẹ̀ mu, o
si fà wọn ya si meji.
13 On si mu agbáda Elijah ti o bọ́ lọwọ
rẹ̀, o si pada sẹhin, o si duro ni bèbe Jor-
dani.
14 On si mu agbáda Elijah ti o bọ́ lọwọ
rẹ̀, o si lù omi na, o si wipe, Nibo ni Ọlu-
wa Ọlọrun Elijah wà? Nigbati on pẹlu si
lù omi na, nwọn si pinyà sihin ati sọhún:
Eliṣa si rekọja.
15 Awọn ọmọ awọn woli ti o wà ni
Jeriko nihà keji si ri i, nwọn si wipe, Ẹmi
Elijah bà le Eliṣa. Nwọn si wá ipade rẹ̀;
nwọn si tẹ̀ ara wọn ba silẹ niwaju rẹ̀.
16 Nwọn si wi fun u pe, Wò o na, ãdọta
ọkọnrin alagbara mbẹ pẹlu awọn iranṣẹ rẹ;
awa bẹ̀ ọ, jẹ ki nwọn ki o lọ, ki nwọn ki o
si wá oluwa rẹ lọ: bọya Ẹmi Oluwa ti gbé
e sokè, o si ti sọ ọ sori ọkan ninu òke nla
wọnni, tabi sinu afonifojì kan. On si
wipe, Ẹ máṣe ranṣẹ.
17 Nigbati nwọn si rọ̀ ọ titi oju fi tì i, o
wi fun wọn pe, Ranṣẹ. Nitorina nwọn
ràn ãdọta ọkọnrin, nwọn si wá a ni ijọ
mẹta, ṣugbọn nwọn kò ri i.
18 Nwọn si tun pada tọ̀ ọ wá, (nitori ni
Jeriko li o joko,) o wi fun wọn pe, Emi kò
ti wi fun nyin pe, Ẹ máṣe lọ?
19 Awọn ọkọnrin ilu na si wi fun Eliṣa
pe, Kiyesi i, itẹ̀do ilu yi dara, bi oluwa mi
ti ri i: ṣugbọn omi buru, ilẹ si ṣá.
20 On si wipe, Mu àwokóto titun kan
fun mi wá, si fi iyọ̀ sinu rẹ̀; nwọn si mu u
tọ̀ ọ wá.
21 On si jade lọ si ibi orisun omi na, o
si dà iyọ na sibẹ, o si wipe, Bayi li Oluwa
wi, Emi ṣe àwotan omi wọnyi; lati ihin lọ,
kì yio si ikú mọ, tabi aṣálẹ.
22 Bẹ̃ni a ṣe àwotan omi na titi di oni
oloni, gẹgẹ bi ọ̀rọ Eliṣa ti o sọ.
23 O si gòke lati ibẹ lọ si Beteli: bi o si
ti ngòke lọ li ọ̀na, awọn ọmọ kekeke jade
lati ilu wá, nwọn si nfi ṣe ẹlẹyà, nwọn si
wi fun u pe, Gòke lọ, apari! gòke lọ,
apari!
24 O si yipada, o si wò wọn, o si fi wọn
bú li orukọ Oluwa. Abo-beari meji si jade
lati inu igbó wá, nwọn si fà mejilelogoji ya
ninu wọn.
25 O si ti ibẹ lọ si òke Karmeli; ati lati
ibẹ o pada si Samaria.

## ORI 3.

JEHORAMU, ọmọ Ahabu si bẹ̀re si ijọba
lori Israeli ni Samaria li ọdun kejidi-
logun Jehoṣafati, ọba Juda, o si jọba li
ọdun mejila.
2 O si ṣe buburu li oju Oluwa; ṣugbọn
kì iṣe bi baba rẹ̀, ati bi iya rẹ̀: nitoriti o
mu ere Baali ti baba rẹ̀ ti ṣe kuro.
3 Ṣugbọn o fi ara mọ ẹ̀ṣẹ Jeroboamu,
ọmọ Nebati, ti o mu Israeli dẹṣẹ; kò si lọ
kuro ninu rẹ̀.
4 Meṣa, ọba Moabu si nsìn agutan, o si
nsan ọkẹ marun ọdọ-agutan, ati ọkẹ marun
àgbo irun fun ọba Israeli.
5 O si ṣe, nigbati Ahabu kú, ọba Moabu
si ṣọ̀tẹ si ọba Israeli.
6 Jehoramu ọba si jade lọ kuro ni Sama-
ria li akoko na, o si ka iye gbogbo Israeli.
7 O si lọ, o ranṣẹ si Jehoṣafati ọba Juda,
wipe, Ọba Moabu ti ṣọ̀tẹ si mi: iwọ o ha
bá mi lọ si Moabu lati jagun? On si wipe,
Emi o gòke lọ: emi bi iwọ, enia mi bi
enia rẹ, ati ẹṣin mi bi ẹṣin rẹ.
8 On si wipe, Ọ̀na wo li awa o gbà gòke
lọ? On si dahùn wipe, Ọ̀na aginju Edomu.
9 Bẹ̃ni ọba Israeli lọ, ati ọba Juda, ati
ọba Edomu: nigbati nwọn rìn àrinyika ijọ
meje, omi kò si si nibẹ fun awọn ogun, ati
fun ẹranko ti ntọ̀ wọn lẹhin.
10 Ọba Israeli si wipe, O ṣe! ti Oluwa
fi pè awọn ọba mẹtẹta wọnyi jọ, lati fi wọn
le Moabu lọwọ!
11 Jehoṣafati si wipe, Kò ha si woli
Oluwa kan nihin, ti awa iba ti ọdọ rẹ̀ bère
lọwọ Oluwa? Ọkan ninu awọn iranṣẹ ọba
Israeli dahùn wipe, Eliṣa, ọmọ Ṣafati ti
ntú omi si ọwọ Elijah mbẹ nihinyi.
12 Jehoṣafati si wipe, Ọ̀rọ Oluwa mbẹ
pẹlu rẹ̀. Bẹ̃ni ọba Israeli ati Jehoṣafati
ati ọba Edomu sọ̀kalẹ tọ̀ ọ lọ.
13 Eliṣa si wi fun ọba Israeli pe, Kili o
ṣe mi ṣe ọ? Ba ara rẹ lọ sọdọ awọn woli
baba rẹ, ati awọn woli iya rẹ. Ọba Israeli
si wi fun u pe, Bẹ̃kọ: nitori ti Oluwa ti pè
awọn ọba mẹtẹta wọnyi jọ, lati fi wọn le
Moabu lọwọ.
14 Eliṣa si wipe, Bi Oluwa awọn ọmọ-
ogun ti mbẹ, niwaju ẹniti emi duro, iba má
ṣepe mo bu ọ̀wọ Jehoṣafati ọba Juda, ni-
tõtọ emi kì ba ti bù ọ wò, bẹ̃ni emi kì ba ti
ri ọ.
15 Ṣugbọn ẹ mu akọrin kan fun mi wá
nisisiyi. O si ṣe, nigbati akọrin na nkọrin,
ọwọ Oluwa si bà le e.
16 On si wipe, Bayi li Oluwa wi, Wà
iho pupọ li afonifojì yi.
17 Nitori bayi li Oluwa wi, pe, Ẹnyin
kì o ri afẹfẹ, bẹ̃ni ẹnyin kì o ri òjo; ṣugbọn
afonifojì na yio kún fun omi, ki ẹnyin ki o

Digitized by Google

le mu, ati ẹnyin, ati awọn ẹran-ọ̀sin nyin,
ati ẹran nyin.
18 Ohun kikini si li eyi loju Oluwa : on
o fi awọn ara Moabu le nyin lọwọ pẹlu.
19 Ẹnyin o si kọlù gbogbo ilu olodi, ati
gbogbo ãyò ilu, ẹnyin o si ké gbogbo igi
rere lulẹ, ẹnyin o si dí gbogbo kanga omi,
ẹnyin o si fi okuta bà gbogbo oko rere jẹ.
20 O si ṣe li owurọ, bi a ti nta ọrẹ-ẹbọ
onjẹ, si kiyesi i, omi ti ọ̀na Edomu wá, ilẹ
na si kún fun omi.
21 Nigbati gbogbo ara Moabu gbọ́ pe,
awọn ọba gòke wá lati ba wọn jà, nwọn kó
gbogbo awọn ti o le hamọra ogun jọ, ati
awọn ti o dagba jù wọn lọ, nwọn si duro li
eti ilẹ wọn.
22 Nwọn si dide li owurọ̀, õrùn si ràn si
oju omi na, awọn ara Moabu si ri omi na li
apakeji, o pọn bi ẹ̀jẹ :
23 Nwọn si wipe, Ẹjẹ li eyi : awọn ọba
na run: nwọn si ti pa ara wọn ; njẹ nisi-
siyi, Moabu, dide si ikogun.
24 Nigbati nwọn si de ibùdo Israeli,
awọn ọmọ Israeli dide, nwọn si kọlù awọn
ara Moabu, nwọn si sa kuro niwaju wọn :
nwọn si wọ inu rẹ̀, nwọn si pa Moabu run.
25 Nwọn si wó gbogbo ilu, olukulùku si
jù okuta tirẹ̀ si gbogbo oko rere, nwọn si
kún wọn ; nwọn si dí gbogbo kanga omi,
nwọn si bẹ́ gbogbo igi rere : ni Kirharaseti
ni nwọn fi kiki awọn okuta rẹ̀ silẹ ṣugbọn
awọn ọnikànakana yi i ka, nwọn si kọlù u.
26 Nigbati ọba Moabu ri i pe ogun na
le jù fun on, o mu ẹdẹgbẹrin ọkọnrin ti o
fà idà yọ pẹlu rẹ̀, lati là ogun ja si ọdọ ọba
Edomu : ṣugbọn nwọn kò le ṣe e.
27 Nigbana li o mu akọbi ọmọ rẹ̀ ti iba
jọba ni ipò rẹ̀, o si fi i rubọ sisun li ori odi.
Ibinu nla si wà si Israeli : nwọn si lọ kuro
lọdọ rẹ̀, nwọn si pada si ilẹ wọn.

## ORI 4.

OBIRIN kan ninu awọn obirin ọmọ awọn
woli ke ba Eliṣa wipe, Iranṣẹ rẹ, ọkọ
mi kú ; iwọ si mọ̀ pe iranṣẹ rẹ bẹ̀ru Oluwa :
awọn onigbèse si wá lati mu awọn ọmọ mi
mejeji li ẹrú.
2 Eliṣa si wi fun u pe, Kini emi o ṣe fun
ọ ? Wi fun mi, kini iwọ ni ninu ile ? On
si wipe, Iranṣẹbirin rẹ kò ni nkankan ni
ile, bikòṣe ikòko ororo kan.
3 On si wipe, Lọ, ki iwọ ki o yá ikòko
lọwọ awọn aladugbò rẹ kakiri, ani ikòko
ofo ; yá wọn, ki iṣe diẹ.
4 Nigbati iwọ ba si wọle, ki iwọ ki o se
ilẹ̀kun mọ ara rẹ, ati mọ awọn ọmọ rẹ, ki o
si dà a sinu gbogbo ikòko wọnni, ki iwọ ki
o si fi eyiti o kún si apakan.
5 O si lọ kuro lọdọ rẹ̀, o si se ilẹ̀kun mọ
ara rẹ̀ ati mọ awọn ọmọ rẹ̀, ti ngbe ikòko
fun u wá ; on si dà a.
6 O si ṣe, nigbati awọn ikòko kún, o wi
fun ọmọ rẹ̀ pe, Tun mu ikòko kan fun mi
wá. On si wi fun u pe, Kò si ikòko kan
mọ. Ororo na si da.
7 Nigbana li o wá, o si sọ fun enia Ọlọrun
na. On si wipe, Lọ, tà ororo na, ki o si
san gbèse rẹ, ki iwọ ati awọn ọmọ rẹ ki o si
jẹ owo ti o kù.
8 O si di ọjọ kan, Eliṣa si kọja si Ṣune-
mu, nibiti obirin ọlọla kan wà ; on si rọ̀ ọ
lati jẹ onjẹ. O si ṣe, nigbakugba ti o ba
nkọja lọ, on a yà si ibẹ lati jẹ onjẹ.
9 On si wi fun ọkọ rẹ̀ pe, Sa wò o na,
emi woye pe, enia mimọ́ Ọlọrun li eyi ti
ngbà ọdọ wa kọja nigbakugba.
10 Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki a ṣe yàrá kekere kan
lara ogiri ; si jẹ ki a gbe ibùsùn kan sibẹ
fun u, ati tabili kan, ati ohun-ijoko kan,
ati ọpá-fitila kan : yio si ṣe, nigbati o ba tọ̀
wa wá, ki on ma wọ̀ sibẹ.
11 O si di ọjọ kan, ti o wá ibẹ̀, o si yà
sinu yàrá na, o si dubulẹ nibẹ.
12 On si wi fun Gehasi iranṣẹ rẹ̀ pe, Pè
ara Ṣunemu yi. Nigbati o si pè e, o duro
niwaju rẹ̀.
13 On si wi fun u pe, nisisiyi, sọ fun u
pe, Kiyesi i, iwọ ti fi gbogbo itọju yi ṣe
aniyàn wa ; kini a ba ṣe fun ọ ? Iwọ nfẹ́
ki a sọ̀rọ rẹ fun ọba bi ? tabi fun olori-
ogun ? On si dahùn wipe, Emi ngbe lãrin
awọn enia mi.
14 On si wipe, Njẹ kini a ba ṣe fun u ?
Gehasi si dahùn pe, Nitõtọ, on kò li ọmọ,
ọkọ rẹ̀ si di arugbo.
15 On si wipe, Pè e wá, nigbati o si ti
pè e de, o duro li ẹnu-ọ̀na.
16 On si wipe, Li akokò yi gẹgẹ bi igba
aiye, iwọ o gbé ọmọkọnrin kan mọra. On
si wipe, Bẹ̃kọ̀, oluwa mi, iwọ enia Ọlọrun,
má ṣe purọ fun iranṣẹ-birin rẹ.
17 Obirin na si loyun, o si bi ọmọkọnrin
kan li akokò na ti Eliṣa ti sọ fun u, gẹgẹ bi
igba aiye.
18 Nigbati ọmọ na si dagba, o di ọjọ
kan, ti o jade tọ̀ baba rẹ̀ lọ si ọdọ awọn
olukore.
19 O si wi fun baba rẹ̀ pe, Ori mi, ori
mi ! On si sọ fun ọmọde kan pe, Gbé e tọ̀
iya rẹ̀ lọ.
20 Nigbati o si gbé e, ti o mu u tọ̀ iya

Digitized by Google

rẹ̀ wá, o joko li ẽkun rẹ̀ titi di ọjọ kanri, o si kú.

21 On si gòke, o si tẹ́ ẹ sori ibùsun enia Ọlọrun na, o si sé ilẹ̀kun mọ ọ, o si jade lọ.

22 On si ke si ọkọ rẹ̀, o si wipe, Emi bẹ̀ ọ, rán ọkan ninu awọn ọdọmọkọnrin si mi, ati ọkan ninu awọn kẹtẹkẹtẹ, emi o si sare tọ̀ enia Ọlọrun lọ, emi o si tun pada.

23 On si wipẹ, Ẽṣe ti iwọ o fi tọ̀ ọ lọ loni? kì isa ṣe oṣù titun, bẽni kì iṣe ọjọ isimi. On sì wipe, Alafia ni.

24 Nigbana li o di kẹtẹkẹtẹ ni gãri, o si wi fun iranṣẹ rẹ̀ pe, Mã le e, ki o si ma nṣo; máṣe dẹ̀ ire fun mi, bikòṣepe mo sọ fun ọ.

25 Bẽli o lọ, o si de ọdọ enia Ọlọrun na li òke Karmeli. O si ṣe, nigbati enia Ọlọrun na ri i li okère, o si sọ fun Gehasi ọmọ-ọdọ rẹ̀ pe, Wò ara Ṣunemu nì:

26 Emi bẹ̀ ọ, sure nisisiyi ki o pade rẹ̀, ki o si wi fun u pe, Alafia ki o wà bi? alafia ki ọkọ rẹ̀ wà bi? alafia ki ọmọde wà bi? On si dahùn wipe, Alafia ni.

27 Nigbati o si de ọdọ enia Ọlọrun li ori òke, o gbá a li ẹsẹ̀ mu: ṣugbọn Gehasi sunmọ ọ lati tì i kurò. Enia Ọlọrun na si wipe, Jọwọ rẹ̀ nitori ọkàn rẹ̀ bajẹ ninu rẹ̀, Oluwa si pa a mọ́ fun mi, kò si sọ fun mi.

28 Nigbana li o wipe, Mo ha tọrọ ọmọ li ọwọ oluwa mi bi? Emi kò ha wipe, Máṣe tàn mi jẹ?

29 O si wi fun Gehasi pe, Di àmure rẹ, ki o si mu ọpá mi li ọwọ rẹ, ki o si lọ, bi iwọ ba ri ẹnikẹni li ọ̀na, máṣe ki i; bi ẹnikẹni ba si kí ọ, máṣe da a li ohùn: ki o si fi ọpá mi le iwaju ọmọ na.

30 Iya ọmọ na si wipe, Bi Oluwa ti mbẹ, ati bi ẹmi rẹ ti mbẹ, emi kì o fi ọ silẹ. On si dide, o si ntọ̀ ọ lẹhin.

31 Gehasi si kọja siwaju wọn, o si fi ọpá na le ọmọ na ni iwaju, ṣugbọn kò si ohùn, tabi afiyesi: nitorina o si tun pada lati lọ ipade rẹ̀, o si wi fun u pe, Ọmọ na kò ji.

32 Nigbati Eliṣa si wọ̀ inu ile, kiyesi i, ọmọ na ti kú, a si tẹ́ ẹ sori ibùsun rẹ̀.

33 O si wọ̀ inu ile lọ, o si se ilẹ̀kun mọ awọn mejeji, o si gbadura si Oluwa.

34 On si gòke, o si dubulẹ le ọmọ na, o si fi ẹnu rẹ̀ le ẹnu rẹ̀, ati oju rẹ̀ le oju rẹ̀, ati ọwọ rẹ̀ le ọwọ rẹ̀: on si nà ara rẹ̀ le ọmọ na, ara ọmọ na si di gbigboná.

35 O si pada, o si rìn lọ rìn bọ̀ ninu ile lẽkan; o si gòke, o si nà ara rẹ̀ le e; ọmọ na si sín nigba meje; ọmọ na si là oju rẹ̀.

36 O si pè Gehasi, o si wipe, Pè ara Ṣunemu yi wá. O si pè e. Nigbati o si wọle tọ̀ ọ wá, o ni, Gbé ọmọ rẹ.

37 Nigbana li o wọ̀ inu ile, o si wolẹ li ẹba ẹsẹ̀ rẹ, o si dojubolẹ, o si gbé ọmọ rẹ̀, o si jade lọ.

38 Eliṣa si tun pada wá si Gilgali, iyàn si mu ni ilẹ na; awọn ọmọ awọn woli joko niwaju rẹ̀: on si wi fun iranṣẹ rẹ̀ pe, Gbe ìkoko nla ka iná, ki ẹ si pa ipẹ̀tẹ fun awọn ọmọ awọn woli.

39 Ẹnikan si jade lọ si igbẹ lati fẹ́ ewebẹ̀, o si ri ajara-igbẹ kan, o si ka eso rẹ̀ kún aṣọ rẹ̀, o si rẹ́ ẹ wẹwẹ, o dà wọn sinu ikoko ipẹ̀tẹ na: nitoripe nwọn kò mọ̀ wọn.

40 Bẽni nwon si dà a fun awọn ọkọnrin na lati jẹ. O si ṣe bi nwọn ti njẹ ipẹ̀tẹ na, nwọn si kigbe, nwọn si wipe, Iwọ enia Ọlọrun, ikú mbẹ ninu ikoko na! Nwọn kò si le jẹ ẹ.

41 Ṣugbọn on wipe, Njẹ, ẹ mu iyẹ̀fun wá. O si dà a sinu ikoko na, o si wipe, Dà a fun awọn enia, ki nwọn ki o le jẹ. Kò si si jamba ninu ikoko mọ.

42 Ọkọnrin kan si ti Baali-Ṣaliṣa wá, o si mu àkara akọso-eso, ogun iṣù àkara barle, ati ṣiri ọkà titun ninu àpo rẹ̀ wá fun enia Ọlọrun na. On si wipe, Fi fun awọn enia, ki nwọn ki o le jẹ.

43 Iranṣẹ rẹ̀ si wipe, Kinla, ki emi ki o gbé eyi kà iwaju ọgọrun enia? On si tun wipe, Fi fun awọn enia, ki nwọn ki o le jẹ: nitori bayi li Oluwa wi pe, Nwọn o jẹ, nwọn o si kù silẹ.

44 Bẽli o gbe e kà iwaju wọn, nwọn si jẹ, nwọn si kù silẹ, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa.

## ORI 5.

NJẸ Naamini, olori-ogun ọba Siria, jẹ enia nla niwaju oluwa rẹ̀, ati ọlọla, nitori nipa rẹ̀ ni Oluwa ti fi iṣẹgun fun Siria: on si jẹ alagbara akọni ọkọnrin, ṣugbọn adẹtẹ̀ ni.

2 Awọn ara Siria si ti jade lọ ni ẹgbẹ́-ẹgbẹ́, nwọn si ti mu ọmọbirin kẹkere kan ni igbèkun lati ilẹ Israeli wá; on si duro niwaju obirin Naamani.

3 On si wi fun iya rẹ̀ pe, oluwa mi iba wà niwaju woli ti mbẹ ni Samaria! nitõtọ on iba wò o sàn kuro ninu ẹ̀tẹ rẹ̀.

4 On si wọle, o si sọ fun oluwa rẹ̀ pe, Bayi bayi li ọmọdebirin ti o ti ilẹ Israeli wá wi.

Digitized by Google

5 Ọba Siria si wipe, Wá na, lọ, emi o si
fi iwe ranṣẹ si ọba Israeli. On si jade lọ, o
si mu talenti fàdakà mẹwa lọwọ, ati ẹgbãta
iwọ̀n wurà, ati ipãrọ aṣọ mẹwa.
6 On si mu iwe na tọ̀ ọba Israeli wá,
wipe, Njẹ nisisiyi nigbati iwe yi ba de
ọdọ rẹ, kiyesi i, emi rán Naamani iranṣẹ
mi si ọ, ki iwọ ki o lẹ wò o sàn kuro ninu
ẹ̀tẹ rẹ̀.
7 O si ṣe, nigbati ọba Israeli kà iwe na
tan, o si fà aṣọ rẹ̀ ya, o si wipe, Emi ha iṣe
Ọlọrun, lati pa ati lati sọ di ãyè, ti eleyi fi
ranṣẹ si mi lati ṣe awòtan enia kan kuro
ninu ẹ̀tẹ rẹ̀? nitorina, ẹ rò o wò, mo bẹ̀
nyin, ki ẹ si wò o bi on ti nwá mi ni ijà.
8 O si ṣe, nigbati Eliṣa enia Ọlọrun gbọ́
pe, ọba Israeli fà aṣọ rẹ̀ ya, o si ranṣẹ si
ọba wipe, Ẽṣe ti iwọ fi fà aṣọ rẹ ya? jẹ ki
o tọ̀ mi wá nisisiyi, on o si mọ̀ pe, woli
kan mbẹ ni Israeli.
9 Bẽni Naamani de pẹlu awọn ẹṣin rẹ̀
ati pẹlu kẹkẹ́ rẹ̀, o si duro li ẹnu-ọ̀na ile
Eliṣa.
10 Eliṣa si rán iranṣẹ kan si i wipe, Lọ,
ki o si wẹ̀ ni Jordani nigba meje, ẹran-ara
rẹ yio si tun bọ̀ sipò fun ọ, iwọ o si mọ́.
11 Ṣugbọ̀n Naamani binu, o si pada lọ,
o si wipe, Kiyesi i, mo rò ninu mi pe,
dajudaju on o jade tọ̀ mi wá, yio si duro,
yio si kepè orukọ Oluwa Ọlọrun rẹ̀, yio si
fi ọwọ rẹ̀ pa ibẹ̀ na, yio si ṣe awòtan ẹ̀tẹ na.
12 Abana ati Farpari, awọn odò Da-
masku kò ha dara jù gbogbo awọn omi
Israeli lọ? emi kì iwẹ̀ ninu wọn ki emi si
mọ́? Bẽli o yipada, o si jade lọ ni irúnu.
13 Awọn iranṣẹ rẹ̀ si sunmọ ọ, nwọn si
ba a sọ̀rọ, nwọn si wipe, Baba mi, woli iba
wi fun ọ pe, ki o ṣe ohun nla kan, iwọ kì
ba ti ṣe e bi? melomelo, nigbati o wi fun
ọ pe, Wẹ̀, ki o si mọ́?
14 Nigbana ni o sọ̀kalẹ, o si tẹ̀ ara rẹ̀ bọ
inu Jordani nigba meje, gẹgẹ bi ọ̀rọ enia
Ọlọrun: ẹran-ara rẹ̀ si tún pada bọ̀ gẹgẹ bi
ẹran-ara ọmọ kekere, on si mọ́.
15 O si pada tọ̀ enia Ọlọrun na lọ, on,
ati gbogbo ẹgbẹ́ rẹ̀, nwọn si wá, nwọn duro
niwaju rẹ̀: on si wipe, wõ, nisisiyi ni mo
to mọ̀ pe, Kò si Ọlọrun ni gbogbo aiye,
bikòṣe ni Israeli: njẹ nisisiyi, emi bẹ̀ ọ,
gbà ẹbùn lọwọ iranṣẹ rẹ.
16 Ṣugbọn on wipe, Bi Oluwa ti mbẹ,
niwaju ẹniti emi duro, emi kì yio gbà
nkan. O si rọ̀ ọ ki o gbà, ṣugbọn on kọ̀.
17 Naamani si wipe, Njẹ emi bẹ̀ ọ, a kì
yio ha fi erupẹ ẹrù ibãka meji fun iranṣẹ
rẹ? nitori lati oni lọ iranṣẹ rẹ kì yio rubọ
sisun, bẽni kì yio rubọ si awọn ọlọrun
miran, bikòṣe si Oluwa.
18 Ninu nkan yi ni ki Oluwa ki o darijì
iranṣẹ rẹ, nigbati oluwa mi ba lọ si ile
Rimmoni lati foribalẹ nibẹ, ti on ba si fi
ara tì ọwọ mi, ti emi tẹ̀ ara mi ba ni ile
Rimmoni: nigbati mo ba tẹ̀ ara mi ba ni
ile Rimmoni, ki Oluwa ki o darijì iranṣẹ
rẹ ninu nkan yi.
19 On si wi fun u pe, Mã lọ li alafia.
Bẽni o si jade lọ jinà diẹ kuro lọdọ rẹ̀.
20 Ṣugbọn Gehasi, iranṣẹ Eliṣa enia Ọlọ-
run na wipe, Kiyesi i, oluwa mi ti dá
Naamani ara Siria yi si, niti kò gbà nkan
ti o mu wá lọwọ rẹ̀: ṣugbọn, bi Oluwa ti
mbẹ, emi o sare bá a, emi o si gbà nkan
lọwọ rẹ̀.
21 Bẽni Gehasi lepa Naamani. Nigbati
Naamani ri ti nsare bọ̀ lẹhin on, o sọ̀kalẹ
kuro ninu kẹkẹ́ lati pade rẹ̀, o si wipe,
Alafia kọ?
22 On si wipe, Alafia ni. Oluwa mi
rán mi, wipe, Kiyesi i, nisisiyi ni ọdọmọ-
kọnrin meji ninu awọn ọmọ woli ti òke
Efraimu wá ọdọ mi; emi bẹ̀ o, fun wọn ni
talenti fadakà kan, ati ipàrọ aṣọ meji.
23 Naamani si wipe, Fi ara balẹ, gbà
talenti meji. On si rọ̀ ọ, o si dì talenti
fadakà meji sinu apò meji, pẹlu ipàrọ aṣọ
meji, o si gbé wọn rù ọmọ-ọdọ rẹ̀ meji;
nwọn si rù wọn niwaju rẹ̀.
24 Nigbati o si de ibi ile ìṣọ, o gbà wọn
lọwọ wọn, o si tò wọn sinu ile: o si jọ̀wọ
awọn ọkọnrin na lọwọ lọ, nwọn si jade lọ.
25 Ṣugbọn on wọ̀ inu ile lọ, o si duro
niwaju oluwa rẹ̀. Eliṣa si wi fun u pe,
Gehasi, nibo ni iwọ ti mbọ̀? On si wipe,
Iranṣẹ rẹ kò lọ ibikibi.
26 On si wi fun u pe, Ọkàn mi kò ha
ba ọ lọ, nigbati ọkọnrin na fi yipada kuro
ninu kẹkẹ́ rẹ̀ lati pade rẹ? Eyi ha iṣe
akokò ati gbà fadakà, ati lati gbà aṣọ, ati
ọgbà-olifi ati ọgbà-ajara, ati agutan, ati
malu, ati iranṣẹkọnrin ati iranṣẹbirin?
27 Nitorina ẹ̀tẹ Naamani yio lẹ mọ ọ,
ati iru-ọmọ rẹ titi lai. On si jade kuro
niwaju rẹ̀, li adẹtẹ̀ ti o funfun bi ojodidì.

## ORI 6.

AWỌN ọmọ awọn woli wi fun Eliṣa pe,
Sa wò o na, ibiti awa gbe njoko ni-
waju rẹ, o há jù fun wa.
2 Jẹ ki awa ki o lọ, awa bẹ̀ ọ, si Jordani,
ki olukulùku wa ki o mu iti igi kọ̃kan wá,
si jẹ ki awa ki o ṣe ibikan, ti awa o ma
gbe. On si dahùn wipe, Ẹ mã lọ.

Digitized by Google

3 Ẹnikan si wipe, Ki o wu ọ, emi bẹ̀ ọ,
lati ba awọn iranṣẹ rẹ lọ. On si dahùn pe,
Emi o lọ.
4 Bẹ̃li o ba wọn lọ. Nigbati nwọn si de
Jordani, nwọn ké igi.
5 O si ṣe, bi ẹnikan ti nké iti-igi, ãke
yọ sinu omi: o si kigbe, o si wipe, Yẽ!
oluwa mi, a tọrọ rẹ̀ ni.
6 Enia Ọlọrun si wipe, Nibo li o bọ́ si?
O si fi ibẹ hàn a. On si ké igi kan, o si
sọ́ ọ sinu rẹ̀; irin na si fó soke.
7 Nitorina o wipe, Mu u. On si nà ọwọ
rẹ̀, o si mu u.
8 Nigbana ni ọba Siria mba Israeli jagun,
o si ba awọn iranṣẹ rẹ̀ gbèro wipe, Ni ibi
bayibayi ni ibùba mi yio gbe wà.
9 Enia Ọlọrun si ranṣẹ si ọba Israeli
wipe, Kiye sara, ki iwọ ki o máṣe kọja si
ibi bayi; nitori nibẹ ni awọn ara Siria
ba si.
10 Ọba Israeli si ranṣẹ si ibẹ na ti enia
Ọlọrun ti sọ fun u, ti o si ti kilọ fun u, o
si gbà ara rẹ̀ nibẹ, kì iṣe nigbà kan tabi
nigba meji.
11 Nitorina li ọkàn ọba Siria bajẹ gidi-
gidi nitori nkan yi: o si pè awọn iranṣẹ
rẹ̀, o si wi fun wọn pe, Ẹnyin kì yio ha
fihan mi, tani ninu wa ti o nṣe ti ọba
Israeli?
12 Ọkan ninu awọn iranṣẹ rẹ̀ si wipe,
Kò si ẹnikan, oluwa mi, ọba; bikoṣe Eliṣa,
woli ti mbẹ ni Israeli, ni nsọ fun ọba
Israeli gbogbo ọ̀rọ ti iwọ nsọ ninu iyẹ̀wu
rẹ.
13 On si wipe, Ẹ lọ iwò ibi ti on gbe
wà, ki emi o le ranṣẹ lọ mu u wá. A si sọ
fun u, wipe, Wò o, o wà ni Dotani.
14 Nitorina li o ṣe rán awọn ẹṣin ati
kẹkẹ́ ati ogun nla sibẹ: nwọn si de li oru,
nwọn si yi ilu na ka.
15 Nigbati iranṣẹ enia Ọlọrun na si dide
ni kùtukutu ti o si jade lọ, wõ, ogun yi ilu
na ka, ati ẹṣin ati kẹkẹ́. Iranṣẹ rẹ̀ si wi
fun u pe, Yẽ! baba mi, awa o ti ṣe?
16 On si dahùn wipe, Má bẹ̀ru: nitori
awọn ti o wà pẹlu wa, jù awọn ti o wà pẹlu
wọn lọ.
17 Eliṣa si gbadura, o si wipe, Oluwa,
emi bẹ̀ ọ, là a li oju, ki o lè riran. Oluwa
si là oju ọdọmọkọnrin na; on si riran: si
wò o, òke na kún fun ẹṣin ati kẹkẹ́-iná yi
Eliṣa ka.
18 Nigbati nwọn si sọ̀kalẹ tọ̀ ọ wá, Eliṣa
gbadura si Oluwa, o si wipe, Emi bẹ̀ ọ, bù
ifọju lù awọn enia yi. On si bù ifọju lù
wọn gẹgẹ bi ọ̀rọ Eliṣa.
19 Eliṣa si wi fun wọn pe, Eyi kì iṣe
ọ̀na, bẹ̃ni eyi kì iṣe ilu na: ẹ ma tọ̀ mi
lẹhin, emi o si mu nyin wá ọdọ ọkọnrin
ti ẹnyin nwá. O si ṣe amọ̀na wọn lọ si
Samaria.
20 O si ṣe, nigbati nwọn de Samaria ni
Eliṣa wipe, Oluwa la oju awọn enia wọnyi,
ki nwọn ki o lè riran. Oluwa si là oju
wọn; nwọn si riran; si kiyesi i, nwọn mbẹ
li ãrin Samaria.
21 Ọba Israeli si wi fun Eliṣa, nigbati o
ri wọn pe, Baba mi, ki emi ki o mã pa
wọn bi? ki emi ki o mã pa wọn bi?
22 On si dahùn pe, Iwọ kò gbọdọ pa
wọn: iwọ jẹ pa awọn ti iwọ fi idà rẹ ati
ọrun rẹ kó ni igbèkun? Gbe onjẹ ati omi
kalẹ niwaju wọn, ki nwọn ki o jẹ, ki nwọn
ki o si mu, ki nwọn ki o si tọ̀ oluwa wọn lọ.
23 On si pèse ọ̀pọlọpọ onjẹ fun wọn;
nigbati nwọn si ti jẹ, ti nwọn si ti mu tan,
o rán wọn lọ, nwọn si tọ̀ oluwa wọn lọ.
Bẹ̃ni ẹgbẹ́ ogun Siria kò tun wá si ilẹ
Israeli mọ.
24 O si ṣe lẹhìn eyi, ni Benhadadi ọba
Siria ko gbogbo ogun rẹ̀ jọ, nwọn si gòke,
nwọn si dó ti Samaria.
25 Iyàn nla kan si mu ni Samaria: si
kiyesi i, nwọn dó tì i, tobẹ̃ ti a si fi ntà
ori kẹtẹkẹtẹ kan ni ọgọrun iwọ̀n fadakà,
ati idamẹrin oṣuwọn kabu imi ẹiyẹle, ni
iwọ̀n fàdakà marun.
26 O si ṣe ti ọba Israeli nkọja lọ lori odi,
obirin kan sọkún tọ̀ ọ wá wipe, Gbà mi,
oluwa mi, ọba!
27 On si wipe, Bi Oluwa kò ba gbà ọ,
nibo li emi o gbe ti gbà ọ? Lati inu ilẹ-
ipakà, tabi lati inu ibi ifunti?
28 Ọba si wi fun u pe, Ẽṣe ọ? On si
dahùn wipe, Obirin yi wi fun mi pe, Mu
ọmọkọnrin rẹ wá, ki awa ki o le jẹ ẹ loni,
awa o si jẹ ọmọ ti emi li ọla.
29 Bẹ̃ni awa sè ọmọ mi, awa si jẹ́ ẹ:
emi si wi fun u ni ijọ keji pe, Mu ọmọ rẹ
wá ki awa ki o jẹ́ ẹ; on si ti fi ọmọ rẹ̀
pamọ́.
30 O si ṣe, nigbati ọba gbọ́ ọ̀rọ obirin
na, o fà aṣọ rẹ̀ ya; o si kọja lọ lori odi,
awọn enia si wò, si kiyesi i, o ni aṣọ-ọfọ̀
labẹ aṣọ rẹ̀ li ara rẹ̀.
31 Nigbana ni o wipe, Ki Ọlọrun ki o
ṣe bayi ati jù bẹ̃ lọ si mi, bi ori Eliṣa ọmọ
Ṣafati yio duro li ọrùn rẹ̀ li oni.
32 Ṣugbọn Eliṣa joko ninu ile rẹ̀, ati
awọn àgbagba joko pẹlu rẹ̀; ọba si rán
ọkọnrin kan ṣãju rẹ̀ lọ: ṣugbọn ki iranṣẹ
na ki o to dé ọdọ rẹ̀, on wi fun awọn àgba-

Digitized by Google

›e, Ẹ wò bi ọmọ apania yi ti ranṣẹ lati
›ri mi kuro? ẹ wò, nigbati iranṣẹ na
›, ẹ tì ilẹkun, ki ẹ si dì i mu ṣinṣin li
›na: iro-ẹsẹ oluwa rẹ kò ha wà lẹhin

Bi on ti mba wọn sọrọ lọwọ, kiyesi
nṣẹ na sọkalẹ tọ ọ wá: on sipe, Wò
›i ọwọ Oluwa ni ibi yi ti wá, kili emi
duro dè Oluwa mọ si?

## ORI 7.

›BANA ni Eliṣa wipe, Ẹ gbọ ọrọ
Oluwa: Bayi li Oluwa wi, Ni iwòyi
› a o ta oṣùwọn iyẹfun kikuna kan ni
i kan ni ẹnu bode Samaria.
Nigbana ni ijòye kan li ọwọ ẹniti ọba
ra tì dá enia Ọlọrun li ohùn, o si wipe,
si i, bi Oluwa tilẹ ṣe ferese li ọrun,
› yi ha le ri bẹ̃? On si wipe, Kiyesi i,
› fi oju rẹ ri i, ṣugbọn iwọ ki yio jẹ
rẹ.
Adẹtẹ mẹrin kan si wà ni atiwọ bodè;
› si wi fun ara wọn pe, Ẽṣe ti awa fi
nihinyi titi awa o fi kú?
Bi awa ba wipe, Awa o wọ ilu lọ, iyàn
bẹ ni ilu, awa o si kú nibẹ: bi awa ba
›ko jẹ nihinyi, awa o kú pẹlu. Njẹ
›iyi ẹ wá, ẹ jẹ ki awa ki o ṣubu si ọwọ
› awọn ara Siria: bi nwọn ba dá wa si,
o yè: bi nwọn ba si pa wa, awa o kú
›i.
Nwọn si dide li afẹmọjumọ lati lọ si
›o awọn ara Siria: nigbati nwọn si de
ti o kangun ibúdo Siria, kiyesi i, kò si
›rin kan nibẹ.
Nitori ti Oluwa ṣe ki ogun awọn ara
› ki o gbọ ariwo kẹkẹ, ati ariwo ẹṣin,
›o ogun nla: nwọn si wi fun ara wọn
Kiyesi i, ọba Israeli ti bẹ ogun awọn
Hitti, ati awọn ọba Egipti si wa, lati
›ò wa mọlẹ.
Nitorina ni nwọn dide, nwọn si salọ
fẹmọjumọ, nwọn si fi agọ wọn silẹ, ati
wọn, ati kẹtẹkẹtẹ wọn, ani, ibùdo wọn
› bi o ti wà, nwọn si salọ fun ẹmi wọn.
Nigbati adẹtẹ wọnyi de apa ikangun
o, nwọn wọ inu agọ kan lọ, nwọn jẹ,
›n si mu, nwọn sì kó fadakà ati wura
›gbáda lati ibẹ lọ, nwọn si lọ, nwọn si
› mọ; nwọn si tún pada wá, nwọn si
›nu agọ miran lọ, nwọn si kó lati ibẹ lọ
›, nwọn si lọ, nwọn si pa a mọ.
Nigbana ni nwọn wi fun ara wọn pe,
› kò ṣe rere: oni yi, ọjọ ihinrere ni,
si dakẹ: bi awa ba duro titi di afẹmọ-
jumọ, iyà yio jẹ wa: njẹ nisisiyi ẹ wá, ẹ jẹ
ki a si lọ isọ fun awọn ara ile ọba.
10 Bẽni nwọn wá, nwọn si ke si awọn
onibodè ilu; nwọn si wi fun wọn pe, Awa
de bùdo awọn ara Siria, si kiyesi i, kò si
ọkọnrin kan nibẹ, bẽni kò si ohùn enia
kan, bikòṣe ẹṣin ti a so, ati kẹtẹkẹtẹ ti a
so, ati agọ bi nwọn ti wà.
11 Ẹnikan si pè awọn onibodè; nwọn
si sọ ninu ile ọba.
12 Ọba si dide li oru, o si wi fun awọn
iranṣẹ rẹ pe, Emi o fi hán nyin nisisiyi
eyiti awọn ara Siria ti ṣe si wa. Nwọn mọ
pe, ebi npa wa; nitorina nwọn jade lọ ni
bùdo lati fi ara wọn pamọ ni igbẹ wipe,
Nigbati nwọn ba jade ni ilu, awa o mu
wọn lãyè, awa o si wọ inu ilu lọ.
13 Ọkan ninu awọn iranṣẹ rẹ si dahùn o
si wipe, Emi bẹ ọ, jẹ ki awa ki o mu ma-
run ninu ẹṣin ti o kù, ninu awọn ti o kù
ni ilu, kiyesi i, nwọn sa dabi gbogbo ọpọ-
lọpọ Israeli ti o kù ninu rẹ; kiyesi i, ani
bi gbogbo ọpọlọpọ enia Israeli ti a run, si
jẹ ki a ranṣẹ lọ iwò.
14 Nitorina nwọn mu ẹṣin kẹkẹ meji;
ọba si ranṣẹ tọ ogun awọn ara Siria lẹhin,
wipe, Ẹ lọ iwò.
15 Nwọn si tọ wọn lẹhin de Jordani: si
wò o, gbogbo ọna kún fun agbáda ati ohun
elò ti awọn ara Siria gbé sọnù ni iyára
wọn. Awọn onṣẹ si pada, nwọn si sọ fun
ọba.
16 Awọn enia si jade lọ, nwọn si kó
ibùdo awọn ara Siria. Bẽni a ntà oṣùwọn
iyẹfun kikunná kan ni ṣekeli kan, ati oṣu-
wọn barle meji ni ṣekeli kan, gẹgẹ bi ọrọ
Oluwa.
17 Ọba si yàn ijòye na, lọwọ ẹniti o nfi
ara tì, lati ṣe itọju ẹnu bodè: awọn enia si
tẹ ẹ mọlẹ ni bodè, o si kú, bi enia Ọlọrun
na ti wi, ẹniti o sọrọ nigbati ọba sọkalẹ tọ
ọ wá
18 O si ṣe, bi enia Ọlọrun na ti sọ fun
ọba, wipe, Oṣùwọn barle meji fun ṣekeli
kan, ati òṣuwọn iyẹfun kikunná kan, fun
ṣekeli kan, yio wà ni iwòyi ọla ni ẹnu
bodè Samaria:
19 Ijòye na si da enia Ọlọrun na li ohùn,
o si wipe, Kiyesi i, nisisiyi, bi Oluwa tilẹ
ṣe ferese li ọrun, iru nkan yi ha le ri bẹ̃?
On si wipe, Kiyesi i, iwọ o fi oju rẹ ri i,
ṣugbọn iwọ kì yio jẹ ninu rẹ.
20 Bẽli o si ri fun u: nitori awọn enia
tẹ ẹ mọlẹ ni ẹnu bodè, o si kú.

Digitized by Google

## ORI 8.

ELIṢA si wi fun obirin na, ọmọ ẹniti o ti sọ di ãyè, wipe, Dide, si lọ, iwọ ati ile rẹ, ki o si ṣe atipo nibikibi ti iwọ ba le ṣe atipo: nitoriti Oluwa pe ìyan: yio si mu pẹlu ni ilẹ, li ọdun meje.

2 Obirin na si dide, o si ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ enia Ọlọrun na: on si lọ pẹlu ile rẹ̀, nwọn si ṣe atipo ni ilẹ awọn ara Filistia li ọdun meje.

3 O si ṣe lẹhin ọdun meje, ni obirin na pada bọ̀ lati ilẹ awọn ara Filistia: on si jade lọ lati kepè ọba nitori ile rẹ̀ ati nitori ilẹ rẹ̀.

4 Ọba si mba Gehasi iranṣẹ enia Ọlọrun na sọ̀rọ, wipe, Mo bẹ̀ ọ, sọ gbogbo ohun nla, ti Eliṣa ti ṣe fun mi.

5 O si ṣe bi o ti nrò fun ọba bi o ti sọ okú kan di ãyè, si kiyesi i, obirin na, ẹniti a sọ ọmọ rẹ̀ di ãyè kepè ọba nitori ile rẹ ati nitori ilẹ rẹ̀. Gehasi si wipe, Oluwa mi, ọba, eyi li obirin na, eyi si li ọmọ rẹ̀ ti Eliṣa sọ di ãyè.

6 Nigbati ọba si bère lọwọ obirin na, o rohin fun u. Ọba si yàn iwẹ̀fa kan fun u, wipe, Mu ohun gbogbo ti iṣe ti rẹ̀ pada fun u, ati gbogbo erè oko lati ọjọ ti o ti fi ilẹ silẹ titi di isisiyi.

7 Eliṣa si wá si Damasku; Benhadadi ọba Siria si nṣe aisàn; a si sọ fun u, wipe, Enia Ọlọrun de ihinyi.

8 Ọba si wi fun Hasaeli pe, Mu ọrẹ lọwọ rẹ, si lọ ipade enia Ọlọrun na, ki o si bère lọwọ Oluwa lọdọ rẹ̀, wipe, Emi o ha sàn ninu arùn yi?

9 Bẽni Hasaeli lọ ipade rẹ̀, o si mu ọrẹ li ọwọ rẹ̀, ani ninu gbogbo ohun rere Damasku, ogoji ẹrù ibakasiẹ, o si de, o si duro niwaju rẹ̀, o si wipe, Ọmọ rẹ Bẹnhadadi ọba Siria rán mi si ọ, wipe, Emi o ha sàn ninu arùn yi?

10 Eliṣa si wi fun u pe Lọ, ki o si sọ fun u pe, Iwọ iba sàn nitõtọ: ṣugbọn Oluwa ti fi hàn mi pẹ, nitõtọ on o kú.

11 On si tẹ̀ oju rẹ̀ mọ ọ gidigidi, titi oju fi tì i; enia Ọlọrun na si sọkun.

12 Hasaeli si wipe, Ẽṣe ti oluwa mi fi nsọkun? On si dahùn pe, Nitoriti mo mọ̀ ibi ti iwọ o ṣe si awọn ọmọ Israeli: awọn odi agbara wọn ni iwọ o fi iná bọ̀, awọn ọdọmọkọnrin wọn ni iwọ o fi idà pa, iwọ o si fọ́ ọmọ wẹwẹ́ wọn tútu, iwọ o si là inu awọn aboyun wọn.

13 Hasaeli si wipe, Ṣugbọn kinla? Iranṣẹ rẹ iṣe aja, ti yio fi ṣe nkan nla yi? Eliṣa si dahùn wipe, Oluwa ti fi hàn mi pe, iwọ o jọba lori Siria.

14 Bẽli o lọ kuro lọdọ Eliṣa, o si de ọdọ oluwa rẹ̀; on si wi fun u pe, Kini Eliṣa sọ fun ọ? On si dahùn wipe, O sọ fun mi pe, Iwọ o sàn nitõtọ.

15 O si ṣe ni ijọ keji ni o mu aṣọ ti o nipọn, o kì i bọ̀ omi, o si tẹ́ ẹ le oju rẹ̀, bẽli o kú. Hasaeli si jọba nipò rẹ̀.

16 Ati li ọdun karun Joramu, ọmọ Ahabu ọba Israeli, Jehoṣafati jẹ ọba Juda: nigbana Jehoramu ọmọ Jehoṣafati ọba Juda bẹ̀rẹ si ijọba.

17 Ẹni ọdun mejilelọgbọn li o jẹ nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun mẹjọ ni Jerusalemu.

18 O si rìn li ọ̀na awọn ọba Israeli, bi ile Ahabu ti ṣe: nitori ọmọbirin Ahabu li o nṣe aya rẹ̀; on si ṣe ibi niwaju Oluwa.

19 Ṣugbọn Oluwa kò fẹ ipa Juda run, nitori Dafidi iranṣẹ rẹ̀, bi o ti ṣe ileri fun u, lati fun u ni imọlẹ ati fun awọn ọmọ rẹ̀ li ọjọ gbogbo.

20 Li ọjọ rẹ̀ ni Edomu ṣọ̀tẹ kuro li abẹ ọwọ Juda, nwọn si jẹ ọba fun ara wọn.

21 Bẽni Joramu rekọja siha Sairi, ati gbogbo awọn kẹkẹ́ pelu rẹ̀: o si dide li oru, o si kọlù awọn ara Edomu ti o yi i ka: ati awọn olori awọn kẹkẹ́: awọn enia si sá wọ inu agọ wọn.

22 Bẽni Edomu ṣọ̀tẹ kuro labẹ ọwọ Juda titi o fi di oni yi. Nigbana ni Libna ṣọ̀tẹ li akokò kanna.

23 Iyokù iṣe Joramu, ati gbogbo ohun ti o ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Juda?

24 Joramu si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a si sin i pẹlu awọn baba rẹ̀ ni ilu Dafidi: Ahasiah ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipọ̀ rẹ̀.

25 Li ọdun kejila Joramu ọmọ Ahabu ọba Israeli, Ahasiah ọmọ Jehoramu ọba Juda bẹ̀rẹ si ijọba.

26 Ẹni ọdun mejilelogun ni Ahasiah jẹ nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba; o si jọba li ọdun kan ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ a si ma je Ataliah, ọmọbirin Omri ọba Israeli.

27 O si rìn li ọ̀na ile Ahabu, o si ṣe ibi niwaju Oluwa, bi ile Ahabu ti ṣe: nitoriti o nṣe ana ile Ahabu.

28 On si lọ pẹlu Joramu ọmọ Ahabu si ogun na ti o mba Hasaeli ọba Siria jà ni Ramoti-Gileadi; awọn ara Siria si ṣa Joramu li ọgbẹ́.

29 Joramu ọba si pada si Jesreeli lati wò ọgbẹ́ ti awọn ara Siria ti ṣa a ni Rama, nigbati o mba Hasaeli ọba Siria ja. Aha-

Digitized by Google

ıh ọmọ Jehoramu ọba Juda sọ̀kalẹ̀ lati wá
'ò Joramu ọmọ Ahabu ni Jesreeli nitoriti
nṣe aisàn.

ORI 9.

ꞮLIṢA woli si pè ọkan ninu awọn ọmọ
ı woli, o si wi fun u pe, Dì amurè ẹ̀gbẹ
, ki o si mu igò ororo yi lọwọ rẹ, ki o si
si Ramoti-Gileadi:
2 Nigbati iwọ ba si de ibẹ, ki iwọ ki o
, Jehu ọmọ Jehoṣafati, ọmọ Nimṣi li
'ari nibẹ, ki o si wọle, ki o si mu u ki o
le kuro lãrin awọn arakọnrin rẹ̀, ki o si
ı u lọ si yàra inu ile lọhun;
3 Ki o si mu igò ororo na, ki o si tú u si
rẹ̀, ki o si wipe, Bayi li Oluwa wi pe,
ıi fi ororo yàn ọ li ọba li ori Israeli. Si
ilẹkun, ki o si sá, má si ṣe duro.
4 Bẽni ọdọmọkọnrin na, ani ọdọmọkọn-
woli na, lọ si Ramoti-Gileadi.
5 Nigbati o si debẹ, kiyesi i, awọn olori-
ın wà ni ijoko; on si wipe, Emi ni iṣẹ
ı si ọ, balogun. Jehu si wipe, Si tani
ıu gbogbo wa? On si wipe, Si ọ, balo-
ı.
6 On si dide, o si wọ̀ inu ile: o si tú
ro na si i li ori, o si wi fun u pe, Bayi
Oluwa Ọlọrun Israeli wipe, Emi ti fi
ro yàn ọ li ọba lori enia Oluwa, lori
ıeli.
Iwọ o si kọlù ile Ahabu oluwa rẹ, ki
. o le gbẹsan ẹjẹ awọn woli iranṣẹ mi,
ẹ̀jẹ 'gbogbo awọn iranṣẹ Oluwa lọwọ
ebeli.
Nitori gbogbo ile Ahabu ni yio ṣe-
: emi o si ké gbogbo ọdọmọkọnrin
o lọdọ Ahabu, ọmọ-ọdọ ati ominra ni
.eli:
Emi o si ṣe ile Ahabu bi ile Jeroboamu
ı Nebati, ati bi ile Baaṣa ọmọ Ahijah;
0 Awọn aja yio si jẹ Jesebeli ni oko
eeli, kì yio si ẹniti yio sinkú rẹ̀. O si
ẹkùn, o si sá lọ.
1 Nigbana ni Jehu jade tọ̀ awọn iranṣẹ
va rẹ̀: ẹnikan si wi fun u pe, Alafia
nitori kini aṣiwère yi ṣe tọ̀ ọ wá? On
i fun wọn pe, Ẹnyin mọ̀ ọkọnrin na ati
rẹ̀.
2 Nwọn si wipe, Eke; sọ fun wa wayi.
si wipe, Bayi bayi li o sọ fun mi wipe,
ı ni Oluwa wi pe, Emi ti fi ororo yàn ọ
a lori Israeli.
3 Nigbana ni nwọn yára, olukulùku si
gbáda rẹ̀, o si fi i si abẹ rẹ̀ lori atẹ̀gun,
ı si fun ipè wipe, Jehu jọba.
Bẽni Jehu ọmọ Jehoṣafati ọmọ Nimṣi

ṣọ̀tẹ si Joramu. (Njẹ Joramu ti nṣọ Ra-
moti-Gileadi, on, ati gbogbo Israeli, nitoriti
Hasaeli ọba Siria:
15 Ṣugbọn Joramu ọba ti pada si Jes-
reeli lati wò ọgbẹ́ ti awọn ara Siria ṣa a,
nigbati o ba Hasaeli ọba Siria jà.) Jehu
si wipe, Bi o ba ṣe ifẹ inu nyin ni, ẹ má jẹ
ki ẹnikẹni ki o jade lọ, tabi ki o yọ́ lọ kuro
ni ilu lati lọ isọ ni Jesreeli.
16 Bẽni Jehu gùn kẹkẹ́, o si lọ si Jes-
reeli; nitori Joramu dùbulẹ nibẹ. Aha-
siah ọba Juda si sọ̀kalẹ lati wá iwò Joramu.
17 Olùṣọ kan si duro ni ile iṣọ ni Jes-
reeli, o si ri ẹgbẹ́ Jehu bi o ti mbọ̀ wá, o si
wipe, Mo ri ẹgbẹ́ kan. Joramu si wipe,
Mu ẹlẹṣin kan, ki o si ranṣẹ lọ ipade wọn,
ki o si wipe, Alafia kọ́?
18 Ẹnikan si lọ lori ẹṣin lati pade rẹ̀, o
si wipe, Bayi li ọba wi pe, Alafia kọ́?
Jehu si wipe, Kini iwọ ni fi alafia ṣe? yi-
pada sẹhin mi. Olùṣọ na si sọ pe, Iranṣẹ
na de ọdọ wọn ṣugbọn kò si tun pada wá
mọ.
19 O si rán ekeji jade lori ẹṣin on si tọ̀
wọn wá, o si wipe, Bayi li ọba wi pe,
Alafia kọ́? Jehu si dahùn wipe, Kini iwọ
ni fi alafia ṣe? yipada sẹhin mi.
20 Olùṣọ na si sọ wipe, On tilẹ de ọdọ
wọn, kò si tun padà wá mọ: wiwọ́ kẹkẹ́
na si dàbi wiwọ́ kẹkẹ́ Jehu ọmọ Nimṣi;
nitoriti o nwọ́ bọ̀ kikankikan.
21 Joramu si wipe, Ẹ dì kẹkẹ́. Nwọn
si dì kẹkẹ́ rẹ̀. Joramu ọba Israeli ati
Ahasiah ọba Juda si jade lọ, olukuluku
ninu kẹkẹ́ rẹ̀, nwọn si jade lọ ipade Jehu,
nwọn si ba a ni oko Naboti ara Jesreeli.
22 O si ṣe, nigbati Joramu ri Jehu li o
wipe, Jehu, Alafia kọ́? On si wipe, Alafia
kini, niwọ̀nbi iwà-agbère Jesebeli ìya rẹ
ati iṣe ajẹ́ rẹ̀ ti pọ̀ tobẹ̃?
23 Joramu si yi ọwọ rẹ̀ pada, o si sá, o si
wi fun Ahasiah pe, Ọtẹ̀ de Ahasiah.
24 Jehu si fi gbogbo agbara rẹ̀ fà ọrun o
si ta Joramu lãrin apa rẹ̀ mejeji, ọfà na si
gbà ọkàn rẹ̀ jade, o si dojubolẹ ninu kẹkẹ́
rẹ̀.
25 Nigbana ni Jehu sọ fun Bidkari balo-
gun rẹ̀, pe, Gbe e ki o si sọ ọ si oko Naboti
ara Jesreeli: sa ranti bi igbati temi tirẹ
jumọ ngùn kẹkẹ́ lẹhin Ahabu baba rẹ̀,
Oluwa ti sọ ọ̀rọ-ìmọ yi sori rẹ̀.
26 Nitõtọ li ana emi ti ri ẹ̀jẹ Naboti ati
ẹ̀jẹ awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, li Oluwa wi;
emi o si san a fun ọ ni oko yi, li Oluwa wi.
Njẹ nitorina, ẹ mu u, ki ẹ si sọ ọ sinu oko
na gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa.



Digitized by Google

27 Ṣugbọn nigbati Ahasiah ọba Juda ri
eyi, o gbà ọ̀na ile ọgba salọ. Jehu si
lepa rẹ̀ o si wipe, Ẹ ta a ninu kẹkẹ́ pẹlu.
Nwọn si ṣe bẽ li atigòke si Guri, ti o wà
leti Ibleamu. O si salọ si Megiddo, o si
kú nibẹ.
28 Awọn iranṣẹ rẹ̀ si gbé e ninu kẹkẹ́ lọ
si Jerusalemu, nwọn si sin i ni bojì rẹ̀ pẹlu
awọn baba rẹ̀ ni ilu Dafidi.
29 Li ọdun ikọkanla Joramu ọmọ Ahabu
ni Ahasiah bẹ̀re si ijọba lori Juda.
30 Nigbati Jehu si de Jesreeli, Jesebeli
gbọ́; on si le tìrõ, o si ta ori rẹ̀, o si yọju
wode ni fèrese.
31 Bi Jehu si ti ngbà ẹnu-ọ̀na wọle, o
wipe, Simri ti o pa oluwa rẹ̀ ri alafia bi?
32 On si gbé oju rẹ̀ si òke fèrese, o si
wipe, Tani nṣe ti emi? tani? Awọn iwẹ̀fa
meji bi mẹta si yọju si i lode.
33 On si wipe, Ẹ tari rẹ̀ silẹ. Nwọn si
tari rẹ̀ silẹ: diẹ ninu ẹ̀jẹ rẹ̀ si ta si ara
ogiri, ati si ara awọn ẹṣin: on si tẹ̀ ẹ mọlẹ.
34 Nigbati o si wọle, o jẹ, o si mu, o si
wipe, Ẹ lọ iwò obirin egun yi wàyi, ki ẹ si
sìn i: nitori ọmọbirin ọba li on iṣe.
35 Nwọn si lọ isin i; ṣugbọn nwọn kó ri
ninu rẹ̀ jù agbari, ati ẹsẹ̀ ati atẹ́lẹwọ rẹ̀ lọ.
36 Nitorina nwọn si tun pada wá, nwọn
si sọ fun u. On si wipe, Eyi li ọ̀rọ Oluwa,
ti o sọ, nipa ọwọ Elijah iranṣẹ rẹ̀ ara Tiṣbi
wipe, Ni oko Jesreeli li awọn aja yio jẹ
ẹran-ara Jesebeli:
37 Okú Jesebeli yio si dàbi imí ni igbẹ́,
ni oko Jesreeli; tobẽ ti nwọn kì yio wipe,
Jesebeli li eyi.

## ORI 10.

AHABU si ni ãdọrin ọmọ ọkọnrin ni
Samaria. Jehu si kọwe, o si ranṣẹ si
Samaria si awọn olori Jesreeli, si awọn
àgbagba, ati si awọn ti ntọ́ awọn ọmọ Aha-
bu, wipe,
2 Njẹ nisisiyi nigbati iwe yi ba ti de
ọdọ nyin, bi o ti jẹpe, awọn ọmọ oluwa
nyin mbẹ lọdọ nyin, ati kẹkẹ́ ati ẹṣin mbẹ
lọdọ nyin, ilu olodi pẹlu ati ihamọra.
3 Ki ẹ wò ẹniti o sàn jùlọ ati ti o si yẹ
jùlọ ninu awọn ọmọ oluwa nyin, ki ẹ gbé e
ka ori-itẹ́ baba rẹ̀, ki ẹ si jà fun ile oluwa
nyin.
4 Ṣugbọn ẹ̀ru bà wọn gidigidi, nwọn si
wipe, Kiyesi i, ọba meji kò duro niwaju rẹ̀:
awa o ha ti ṣe le duro?
5 Ati ẹniti iṣe olori ile, ati ẹniti iṣe olori
ilu, awọn àgbagba pẹlu, ati awọn olutọ́
awọn ọmọ, ranṣẹ si Jehu wipe, Iranṣẹ rẹ li
awa, a o si ṣe gbogbo ohun ti o ba pa li aṣẹ
fun wa; awa kì yio jẹ ọba: iwọ ṣe eyi ti o
dara li loju rẹ.
6 Nigbana ni o kọ iwe lẹrinkeji si wọn
wipe, Bi ẹnyin ba ṣe ti emi, bi ẹnyin o si
fi eti si ohùn mi, ẹ mu ori awọn ọkọnrin
na, awọn ọmọ oluwa nyin, ki ẹ si tọ̀ mi
wá ni Jesreeli ni iwòyi ọla. Njẹ awọn
ọmọ ọba, ãdọrin ọkọnrin, mbẹ pẹlu awọn
enia nla ilu na ti ntọ́ wọn.
7 O si ṣe, nigbati iwe na de ọdọ wọn, ni
nwọn mu awọn ọmọ ọba, nwọn si pa ãdọrin
ọkọnrin, nwọn si kó ori wọn sinu agbọ̀n,
nwọn si fi wọn ranṣẹ si i ni Jesreeli.
8 Onṣẹ kan si de, o si sọ fun u, wipe,
nwọn ti mu ori awọn ọmọ ọba wá. On si
wipe, Ẹ tò wọn li okiti meji ni atiwọ̀ ẹnu
bodè, titi di owurọ̀.
9 O si ṣe li owurọ̀, o si jade lọ, o si duro,
o si wi fun gbogbo awọn enia pe, Olododo
li ẹnyin: kiyesi i, emi ṣọ̀tẹ si oluwa mi,
mo si pa a: ṣugbọn tani pa gbogbo awọn
wọnyi?
10 Njẹ ẹ mọ̀ pe, kò si ohunkan ninu ọ̀rọ
Oluwa, ti Oluwa sọ niti ile Ahabu ti yio bọ́
silẹ, nitori ti Oluwa ti ṣe eyi ti o ti sọ nipa
ọwọ Elijah iranṣẹ rẹ̀.
11 Bẽni Jehu pa gbogbo awọn ti o kù
ni ile Ahabu ni Jesreeli ati gbogbo awọn
enia nla rẹ̀, ati awọn ibatan rẹ̀, ati awọn
alufa rẹ̀, titi on kò fi kù ọkan silẹ fun u.
12 On si dide, o si mbọ̀ o si wá si Sama-
ria: bi o si ti wà nibi ile irẹ́run agutan li
oju ọ̀na.
13 Jehu pade awọn arakọnrin Ahasiah
ọba Juda, o si wipe, Tali ẹnyin? Nwọn si
dahùn wipe, Awa arakọnrin Ahasiah ni;
awa si nsọ̀kalẹ lati lọ ikí awọn ọmọ ọba ati
awọn ọmọ ayaba.
14 On si wipe, Ẹ mu wọn lãyè, nwọn si
mu wọn lãyè, nwọn si pa wọn nibi iho ile
irẹ́run agùtan, ani ọkọnrin mejilelogoji,
bẽni kò si kù ẹnikan wọn.
15 Nigbati o si jade nibẹ, o ri Jehona-
dabu ọmọ Rekabu mbọ̀wá ipade rẹ̀; o si
sure fun u, o si wi fun u pe, Ọkàn rẹ ha ṣe
dede bi ọkàn mi ti ri si ọkàn rẹ? Jehona-
dabu si dahùn wipe, Bẽni. Bi bẽni, njẹ
fun mi li ọwọ rẹ. O si fun u li ọwọ rẹ̀; on
si fà a sọdọ rẹ̀ sinu kẹkẹ́.
16 On si wipe, Ba mi lọ ki o si wò itara
mi fun Oluwa. Bẽni nwọn mu u gùn kẹkẹ́
rẹ̀.
17 Nigbati o si de Samaria, o pa gbogbo
awọn ti o kù fun Ahabu ni Samaria, titi o

Digitized by Google

fi run u, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa ti o sọ fun Elijah.
18 Jehu si kó gbogbo awọn enia jọ, o si wi fun wọn pe, Ahabu sìn Baali diẹ, ṣugbọn Jehu yio sìn i pupọ.
19 Njẹ nitorina, ẹ pè gbogbo awọn woli Baali fun mi, gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀ ati gbogbo awọn alufa rẹ̀; máṣe jẹ ki ọkan ki o kù; nitoriti mo ni ẹbọ nla iṣe si Baali: ẹnikẹni ti o ba kù, kì yio yè. Ṣugbọn Jehu fi ẹ̀tan ṣe e, nitori ki o le pa awọn olùsin Baali run.
20 Jehu si wipe, Ẹ yà apejọ si mimọ́ fun Baali; nwọn si kede rẹ̀.
21 Jehu si ranṣẹ si gbogbo Israeli; gbogbo awọn olùsin Baali si wá tobẽ ti kò si kù ọkọnrin kan ti kò wá. Nwọn si wá sinu ile Baali; ile Baali si kún lati ikangun ekini titi de ekeji.
22 On si wi fun ẹniti o wà lori yará babalorìṣa pe, Kó aṣọ wá fun gbogbo awọn olùsin Baali. On si kó aṣọ jade fun wọn wá.
23 Jehu si lọ, ati Jehonadabu ọmọ Rekabu sinu ile Baali, o si wi fun awọn olùsin Baali pe, Ẹ wá kiri, ki ẹ si wò ki ẹnikan ninu awọn iranṣẹ Oluwa ki o má si pẹlu nyin nihin, bikòṣe kìki awọn olùsin Baali.
24 Nigbati nwọn si wọle lati ru ẹbọ ati ọrẹ-sisun, Jehu yàn ọgọrin ọkọnrin si ode, o si wipe, Bi ẹnikan ninu awọn ọkọnrin ti mo mu wá fi le nyin lọwọ ba lọ, ẹniti o ba jẹ ki o lọ, ẹmi rẹ̀ yio lọ fun ẹmi tirẹ̀.
25 O si ṣe, bi a si ti pari ati ru ẹbọ sisun, ni Jehu wi fun awọn olùṣọ ati awọn olori-ogun pe, Wọle, ki ẹ si pa wọn; ẹ máṣe jẹ ki ẹnikan ki o jade. Nwọn si fi oju idà pa wọn; awọn olùṣọ ati awọn olori-ogun si gbé wọn sọ si ode, nwọn si wọ̀ inu odi ile Baali.
26 Nwọn si kó awọn ere lati ile Baali jade, nwọn si sun wọn.
27 Nwọn si wo ere Baali lulẹ, nwọn si wo ile Baali lulẹ, nwọn si ṣe e ni ile igbẹ́ titi di oni yi.
28 Bayi ni Jehu pa Baali run kuro ni Israeli.
29 Ṣugbọn Jehu kò kuro ninu ẹ̀ṣẹ Jeroboamu ọmọ Nebati, ti o mu Israeli ṣẹ̀, eyini ni, awọn ẹgbọ̀rọ malu wura ti o wà ni Beteli, ati eyiti o wà ni Dani.
30 Oluwa si wi fun Jehu pe, Nitoriti iwọ ti ṣe rere ni ṣiṣe eyi ti o tọ́ li oju mi, ti o si ti ṣe si ile Ahabu gẹgẹ bi gbogbo eyiti o wà li ọkàn mi, awọn ọmọ rẹ iran kẹrin yio joko lori itẹ Israeli.
31 Ṣugbọn Jehu kò ṣe akiyesi lati ma fi gbogbo ọkàn rẹ̀ rin ninu ofin Oluwa Ọlọrun Israeli: nitoriti kò yà kuro ninu ẹ̀ṣẹ Jeroboamu, ti o mu Israeli ṣẹ̀.
32 Li ọjọ wọnni Oluwa bẹ̀rẹ si iké Israeli kuru: Hasaeli si kọlù wọn ni gbogbo agbègbe Israeli;
33 Lati Jordani nihà ilà-õrùn, gbogbo ilẹ Gileadi, awọn enia Gadi, ati awọn enia Reubeni, ati awọn enia Manasse, lati Aroeri, ti o wà leti odò Arnoni, ani Gileadi ati Baṣani.
34 Ati iyokù iṣe Jehu, ati gbogbo ohun ti o ṣe, ati gbogbo agbara rẹ̀, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Israeli?
35 Jehu si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀: nwọn si sìn i ni Samaria. Jehoahasi ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
36 Ọjọ ti Jehu jọba lori Israeli ni Samaria sì jẹ ọdun mejidilọgbọ̀n.

## ORI 11.

NIGBATI Ataliah iyá Ahasiah si ri pe ọmọ on kú, o dide, o si pa gbogbo iru-ọmọ ọba run.
2 Ṣugbọn Jehoṣeba ọmọbirin Joramu ọba, arabirin Ahasiah, mu Joaṣi ọmọ Ahasiah, o si ji i gbé kuro ninu awọn ọmọ ọba ti a pa; nwọn si pa a mọ́ ninu iyẹ̀wu kuro lọdọ Ataliah, on, ati alagbatọ́ rẹ̀, ti a kò si fi pa a.
3 A si pa a mọ́ pẹlu rẹ̀ ni ile Oluwa li ọdun mefa. Ataliah si jọba lori ilẹ na.
4 Li ọdun keje Jehoiada si ranṣẹ o si mu awọn olori lori ọ̀rọ́rún, pẹlu awọn balogun, ati awọn olùṣọ, o si mu wọn wá si ọdọ rẹ̀ sinu ile Oluwa, o si ba wọn da majẹmu, o si mu wọn bura ni ile Oluwa, o si fi ọmọ ọba hàn wọn.
5 O si paṣẹ fun wọn wipe, Eyi ni nkan ti ẹnyin o ṣe; Idamẹta nyin ti nwọle li ọjọ isimi, yio ṣe olùtọju iṣọ ile ọba;
6 Idamẹta yio si wà li ẹnu ọ̀na Ṣuri; idamẹta yio si wà li ẹnu-ọ̀na lẹhin ẹ̀ṣọ: bẽli ẹnyin o tọju iṣọ́ ile na, lati da abo bò o.
7 Ati idajì gbogbo ẹnyin ti njade lọ li ọjọ isimi, ani awọn ni yio tọju iṣọ ile Oluwa yi ọba ka.
8 Ẹnyin o si pa àgbo yi ọba ka, olukuluku pẹlu ohun ijà rẹ̀ li ọwọ rẹ̀; ẹniti o ba si wọ̀ arin ẹgbẹ́ ogun na, ki a pa a: ki ẹnyin ki o si wà pẹlu ọba bi o ti njade lọ, ati bi o ti mbọ̀wá ile.

Digitized by Google

9 Awọn olori ọrọrun ṣe gẹgẹ bi gbogbo
eyiti Jehoiada alufa pa li aṣẹ: olukuluku
wọn si mu awọn ọkọnrin tirẹ ti ibá wọle
wá li ọjọ isimi, pẹlu awọn ti iba jade lọ li
ọjọ isimi, nwọn si wá si ọdọ Jehoiada alufa.
10 Alufa na si fi ọ̀kọ ati asà Dafidi ọba
ti o wà ni ile Oluwa fun awọn olori ọ̀rọrún.
11 Awọn ẹ̀ṣọ si duro, olukulùku pẹlu
ohun ijà rẹ̀ lọwọ rẹ̀ yi ọba ka, lati igun
ọtún ile Oluwa, titi de igun osì ile Oluwa,
nihà pẹpẹ ati ile Oluwa.
12 On si mu ọmọ ọba na jade wá o si fi
ade de e lori, o si fun u ni iwe-ẹ̀ri; nwọn
si fi i jọba, nwọn si fi ororo yàn a; nwọn
si pàtẹwọ wọn, nwọn si wipe, Ki ọba ki o
pẹ.
13 Nigbati Ataliah gbọ́ ariwo awọn ẹ̀ṣọ
ati ti awọn enia, o tọ̀ awọn enia na wá ni-
nu ile Oluwa.
14 Nigbati o si wò, kiyesi i, ọba duro ni
ibuduro na, gẹgẹ bi iṣe wọn, ati awọn ba-
logun, ati awọn afunpè duro lọdọ ọba;
gbogbo enia ilẹ na si yọ̀, nwọn si fun ipè:
Ataliah si fa aṣọ rẹ̀ ya, o si kigbe, pe, Ọtẹ̀!
Ọtẹ̀!
15 Ṣugbọn Jehoiada alufa paṣẹ fun awọn
olori ọ̀rọrún, ati awọn olori ogun, o si wi
fun wọn pe, Ẹ mu u jade lati inu ile arin
ẹgbẹ ogun: ẹniti o ba si tọ̀ ọ lẹhin ni ki ẹ
fi idà pa. Nitoriti alufa na ti wipe, Ki a
máṣe pa a ninu ile Oluwa.
16 Nwọn si gbé ọwọ le e; on si gbà ọ̀na
ti awọn ẹṣin ngbà wọ̀ ile ọba: nibẹ ni a si
pa a.
17 Jehoiada si da majẹmu lãrin Oluwa
ati ọba ati awọn enia, pe, ki nwọn ki o mã
ṣe enia Oluwa; ati lãrin ọba pẹlu awọn
enia.
18 Gbogbo enia ilẹ na si lọ sinu ile
Baali, nwọn si wo o lulẹ: awọn pẹpẹ rẹ̀
ati awọn ere rẹ̀ ni nwọn fọ́ tútu patapata,
nwọn si pa Mattani alufa Baali niwaju
pẹpẹ na. Alufa na si yàn awọn olori si
ile Oluwa.
19 On si mu awọn olori ọ̀rọrún, ati
awọn olori ogun, ati awọn ẹ̀ṣọ, ati gbogbo
enia ilẹ na; nwọn si mu ọba sọ̀kalẹ lati
ile Oluwa wá, nwọn si gbà oju ẹnu-ọ̀na
ẹ̀ṣọ wọ̀ ile ọba. O si joko lori itẹ awọn
ọba.
20 Gbogbo awọn enia ilẹ na si yọ̀, ilu
na si tòro; nwọn si fi idà pa Ataliah li eti
ile ọba.
21 Ẹni ọdun meje ni Jehoaṣi nigbati o
bẹ̀rẹ si ijọba.

## ORI 12.

LI ọdun keje Jehu ni Jehoaṣi bẹ̀rẹ si
ijọba; ogoji ọdun li o si jọba ni Jerusa-
lemu. Orukọ iyà rẹ̀ a mã jẹ Sibiah ti
Beerṣeba.
2 Jehoasi si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa
li ọjọ rẹ̀ gbogbo ninu eyiti Jehoiada alufa
nkọ́ ọ.
3 Kiki ibi giga wọnnì ni a kò mu kuro:
awọn enia nrubọ, nwọn si nsun turari sibẹ
ni ibi giga wọnni.
4 Jehoaṣi si wi fun awọn alufa pe, Gbo-
gbo owo ti a yà si mimọ́ ti a si mu wá
sinu ile Oluwa, ani olukuluku owo ti
o kọja, ati owo idiyele olukuluku, ati
gbogbo owo ti o ti inu ọkàn olukuluku
wá lati mu wá sinu ile Oluwa.
5 Ẹ jẹ ki awọn alufa ki o mu u tọ̀ ara
wọn, olukuluku lati ọwọ ojulùmọ rẹ̀: ẹ
si jẹ ki nwọn ki o tun ẹya ile na ṣe,
nibikibi ti a ba ri ẹya.
6 O si ṣe, li ọdun kẹtalelogun Jehoaṣi
ọba, awọn alufa kò iti tun ẹya ile na ṣe.
7 Nigbana ni Jehoaṣi ọba pè Jehoiada
alufa, ati awọn alufa miràn, o si wi fun
wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin kò tun ẹya ile na
ṣe? njẹ nisisiyi ẹ máṣe gbà owo mọ lọwọ
awọn ojulùmọ nyin, bikòṣepe ki ẹ fi i lelẹ
fun ẹya ile na.
8 Awọn alufa si jẹ ọ̀hẹn lati má gbà
owo lọwọ awọn enia mọ, tabi lati má tun
ẹya ile na ṣe.
9 Ṣugbọn Jehoiada alufa mu apoti kan,
o si dá ideri rẹ̀ lu, o si fi i si ẹba pẹpẹ
na, li apa ọtún bi ẹnikan ti nwọ̀ inu ile
Oluwa lọ: awọn alufa ti o si ntọju iloro
na fi gbogbo owo ti a mu wá inu ile Oluwa
sinu rẹ̀.
10 O si ṣe, nigbati nwọn ri pe, owo
pupọ̀ mbẹ ninu apoti na, ni akọwe ọba,
ati olori alufa gòke wá, nwọn si dì i sinu
apò, nwọn si kà iye owo ti a ri ninu ile
Oluwa.
11 Nwọn si fi owo na ti a kà le ọwọ
awọn ti o nṣiṣẹ na, awọn ti o nṣe abojuto
ile Oluwa: nwọn si ná a fun awọn gbẹ-
nagbẹna, ati awọn akọle, ti nṣiṣẹ ile Oluwa.
12 Ati fun awọn ọmọle, ati awọn agbẹ́-
kuta, ati lati rà itì-igi ati okuta gbígbẹ
lati tun ẹya ile Oluwa ṣe, ati fun gbogbo
eyi ti a ná fun ile na lati tun u ṣe.
13 Ṣugbọn ninu owo ti a mu wá sinu
ile Oluwa, a kò fi ṣe ọpọ́n fadakà, aluma-
gàji fitila, awokoto, ipè ohun èlo wura tabi
ohun elò fadakà kan fun ile Oluwa:

Digitized by Google

Ṣugbọn nwọn fi i fun awọn ti nṣiṣẹ
wọn si fi tun ile Oluwa ṣe.
Nwọn kò si ba awọn ọkọnrin na ṣirò,
ọ ẹniti nwọn fi owo na le, lati fi fun
ti nṣiṣẹ; nitoriti nwọn ṣe otitọ.
Owo ẹbọ irekọja ati owo ẹbọ ẹ̀ṣe
kò mu wá sinu ile Oluwa: ti awọn
ni.
Nigbana ni Hasaeli ọba Siria gòke
si ba Gati jà, o si kó o: Hasaeli si
rẹ̀ kọ ati gòke lọ si Jerusalemu.
Jehoaṣi ọba Juda si mu gbogbo ohun
nimọ́ ti Jehoṣafati, ati Jehoramu, ati
siah awọn baba rẹ̀, awọn ọba Juda ti
mimọ́, ati ohun mimọ́ tirẹ̀, ati gbogbo
ı ti a ri nibi iṣura ile Oluwa, ati ni ile
o si rán a si Hasaeli ọba Siria: on
kuro ni Jerusalemu.
Ati iyokù iṣe Joaṣi, ati ohun gbogbo
ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ
n ọba Juda?
) Awọn iranṣẹ rẹ̀ si dide, nwọn si di
ṣi, nwọn si pa Joaṣi ni ile Millo, ti o
ılẹ lọ si Silla.
l Nitori Josakari ọmọ Simeati ati Je-
ıbadi ọmọ Ṣomeri, awọn iranṣẹ rẹ̀ pa
si kú; nwọn si sin i pẹlu awọn baba
ıi ilu Dafidi: Amasiah ọmọ rẹ̀ si jọba
pò rẹ̀.

## ORI 13.

: ọdun kẹtalelogun Joaṣi ọmọ Ahasiah
ọba Juda, Jehoahasi ọmọ Jehu bẹ̀rẹ si
ıa lori Israeli ni Samaria.
On si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa,
i tẹ̀le ẹ̀ṣẹ Jerboamu ọmọ Nebati, ẹniti
ıu Israeli ṣẹ̀: on kò si lọ kuro ninu rẹ̀.
3 Ibinu Oluwa si rú si Israeli, o si fi
n le ọwọ Hasaeli ọba Siria, ati le ọwọ
nhadadi ọmọ Hasaeli, li ọjọ wọn gbogbo.
4 Jehoahasi si bẹ̀ Oluwa, Oluwa si gbọ́
ẹ̀; nitoriti o ri inira Israeli, nitoriti ọba
ia ni wọn lara.
5 Oluwa si fun Israeli ni olugbala kan,
ni nwọn si bọ́ lọwọ awọn ara Siria: awọn
ıọ Israeli si joko ninu agọ wọn bi ìgba
jọ.
6 Ṣugbọn nwọn kò lọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ ile
roboamu, ẹniti o mu Israeli ṣẹ̀, ṣugbọn
vọn rìn ninu rẹ̀: ere-oriṣa si wà ni Samaria
lu.
7 Bẽni kò kù ninu awọn enia fun Je-
ıahasi, bikòṣe ãdọta ẹlẹṣin, ati kẹkẹ́
ẹwa, ati ẹgbãrin ẹlẹsẹ̀; nitoriti ọba Siria
pa wọn run, o si ti lọ̀ wọn mọlẹ bi ẽkuru.
8 Ati iyokù iṣe Jehoahasi, ati gbogbo
eyiti o ṣe, ati agbara rẹ̀, a kò ha kọ wọn
sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Israeli.
9 Jehoahasi si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀;
nwọn si sin i ni Samaria: Joaṣi ọmọ rẹ̀
si jọba ni ipò rẹ̀.
10 Li ọdun kẹtadilogoji Joaṣi ọba Juda,
Jehoaṣi ọmọ Jehoahasi bẹ̀rẹ si ijọba lori
Israeli ni Samaria, o si jọba li ọdun
mẹrindilogun.
11 On si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa;
on kò lọ kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ Jeroboamu
ọmọ Nebati, ẹniti o mu Israeli ṣẹ̀: ṣugbọn
o rìn ninu wọn.
12 Ati iyokù iṣe Joaṣi, ati ohun gbogbo
ti o ṣe, ati agbara rẹ̀ ti o fi ba Amasiah
ọba Juda jà, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
ọjọ awọn ọba Israeli?
13 Joaṣi si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀; Je-
roboamu si joko lori itẹ́ rẹ̀: a si sin Joaṣi
ni Samaria pẹlu awọn ọba Israeli.
14 Eliṣa si ṣe aisàn ninu aisàn rẹ̀ na
ti o fi kú, Joaṣi ọba Israeli si sọ̀kalẹ tọ̀
ọ wá, o si sọkun si i li oju, o si wipe,
Baba mi, baba mi! kẹkẹ́ Israeli, ati awọn
ẹlẹṣin rẹ̀!
15 Eliṣa si wi fun u pe, Mu ọrun pẹlu
ọfà: on si mu ọrun ati ọfà.
16 O si wi fun ọba Israeli pe, Fi ọwọ
rẹ le ọrun na: on si fi ọwọ rẹ̀ le e: Elisa
si fi ọwọ tirẹ̀ le ọwọ ọba.
17 O si wipe, Ṣi fèrese ilà õrùn. On si
ṣi i. Nigbana ni Eliṣa wipe, Ta. On si
ta. O si wipe, Ọfà igbala Oluwa, ati ọfà
igbala lọwọ Siria: nitori iwọ o kọlù awọn
ara Siria ni Afeki, titi iwọ o fi run wọn.
18 O si wipe, Kó awọn ọfà na. O si kó
wọn. O si wi fun ọba Israeli pe, Ta si
ilẹ. On si ta larinmẹta, o si mu ọwọ duro.
19 Enia Ọlọrun na si binu si i, o si
wipe, Iwọ iba ta larin marun tabi mẹfa;
nigbana ni iwọ iba kọlù Siria titi iwọ iba
fi run u: ṣugbọn nisisiyi iwọ o kọlù Siria
nigbà mẹta.
20 Eliṣa si kú, nwọn si sin i. Ẹgbẹ́
awọn ara Moabu si gbé ogun wá ilẹ na li
amọdun.
21 O si ṣe, bi nwọn ti nsinkú ọkọnrin
kan, si kiye si i, nwọn ri ẹgbẹ́ kan; nwọn
si jù ọkọnrin na sinu isà-okú Eliṣa; ni-
gbati a si sọ ọ silẹ, ti ọkọnrin na fi ara
kàn egungun Eliṣa, o si sọji, o si dide duro
li ẹsẹ̀ rẹ̀.
22 Ṣugbọn Hasaeli ọba Siria ni Israeli
lara ni gbogbo ọjọ Jehoahasi.
23 Oluwa si ṣe oju rere si wọn, o si ṣãnu
fun wọn, o si ṣe akiyesi wọn, nitoriti

Digitized by Google

majẹmu rẹ̀ pẹlu Abrahamu, Isaaki, ati
Jakobu, kò si fẹ run wọn, bẽni kò si ta
wọn nù kuro niwaju rẹ̀ titi di isisiyi.
24 Bẽni Hasaeli ọba Siria kú; Benha-
dadi ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
25 Jehoaṣi ọmọ Jehoahasi si tun gbà
ilu wọnni pada lọwọ Benhadadi ọmọ Ha-
saeli, ti o ti fi ogun gbà lọwọ Jehoahasi
baba rẹ̀. Igba mẹta ni Joaṣi ṣẹgun rẹ̀, o
si gbà awọn ilu Israeli pada.

ORI 14.

LI ọdun keji Joaṣi ọmọ Jehoahasi ọba
Israeli ni Amasiah ọmọ Joaṣi jọba
lori Juda.
2 Ẹni ọdun mẽdọgbọ̀n li on iṣe nigbati
o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun mọkandi-
lọgbọ̀n ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ a si
ma jẹ Jehoadani ti Jerusalemu.
3 On si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa, ṣugbọn
kì iṣe bi Dafidi baba rẹ̀: o ṣe gẹgẹ bi ohun
gbogbo ti Joaṣi baba rẹ̀ ti ṣe.
4 Kiki a kò mu ibi giga wọnni kuro;
sibẹ awọn enia nṣe irubọ, nwọn si nsun tu-
rari ni ibi giga wọnni.
5 O si ṣe bi ijọba na ti fi idi mulẹ lọwọ
rẹ̀ ni o pa awọn iranṣẹ rẹ̀ ti o ti pa ọba
baba rẹ̀.
6 Ṣugbọn awọn ọmọ awọn apania na ni
kò pa: gẹgẹ bi eyiti a ti kọ ninu iwe ofin
Mose ninu eyiti Oluwa paṣẹ wipe, A kò
gbọdọ pa baba fun ọmọ, bẽni a kò gbọdọ
pa ọmọ fun baba; ṣugbọn olukuluku li a o
pa fun ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
7 On pa ẹgbãrun ninu awọn ara Edomu
ni afonifojì iyọ, o si fi ogun kó Sela, o si pè
orukọ rẹ̀ ni Jokteeli titi di oni yi.
8 Nigbana ni Amasiah rán ikọ̀ si Jeho-
aṣi, ọmọ Jehoahasi ọmọ Jehu, ọba Israeli
wipe, Wá, jẹ ki a wò ara wa li oju.
9 Jehoaṣi ọba Israeli si ranṣẹ si Amasiah
ọba Juda, pe, Igi ẹgún ti mbẹ ni Lebanoni
ranṣẹ si igi kedari ti mbẹ ni Lebanoni pe,
Fi ọmọbirin rẹ fun ọmọ ọkọnrin mi li aya:
ẹranko igbẹ́ kan ti mbẹ ni Lebanoni kọja
lọ, o si tẹ̀ igi ẹ̀gun na mọlẹ.
10 Iwọ ti ṣẹgun Edomu nitõtọ, ọkàn rẹ
si gbé ọ soke: mã ṣogo, ki o si gbe ile rẹ:
nitori kini iwọ ṣe nfiràn si ifarapa rẹ, ki
iwọ ki o lè ṣubu, iwọ, ati Juda pẹlu rẹ?
11 Ṣugbọn Amasiah kò fẹ igbọ́. Nito-
rina Jehoaṣi ọba Israeli gòke lọ; on ati
Amasiah ọba Juda si wò ara wọn li oju ni
Betṣemeṣi, ti iṣe ti Juda.
12 A si le Juda niwaju Israeli; nwọn si
sá olukuluku sinu agọ rẹ̀.
13 Jehoaṣi ọba Israeli si mu Amasiah
ọba Juda, ọmọ Jehoaṣi ọmọ Ahasiah ni
Betṣemeṣi, o si wá si Jerusalemu, o si wó
odi Jerusalemu palẹ lati ẹnu bodè Efraimu
titi de ẹnu bodè igun, irinwo igbọnwọ.
14 O si kó gbogbo wura ati fadakà, ati
gbogbo ohun èlo ti a ri ninu ile Oluwa, ati
ninu iṣura ile ọba, ati ògo, o si pada si
Samaria.
15 Ati iyokù iṣe Jehoaṣi ti o ṣe, ati
agbara rẹ̀, ati bi o ti ba Amasiah ọba Juda
jà, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn
ọba Israeli?
16 Jehoaṣi si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a
si sin i ni Samaria pẹlu awọn ọba Israeli;
Jeroboamu ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
17 Amasiah ọmọ Joaṣi ọba Juda wà li
ọdun mẽdogun lẹhin ikú Jehoaṣi ọmọ
Jehoahasi ọba Israeli.
18 Ati iyokù iṣe Amasiah, a kò ha kọ
wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Juda?
19 Nwọn si dì rikiṣi si i ni Jerusalemu:
o si salọ si Lakiṣi; ṣugbọn nwọn ranṣẹ tọ̀
ọ ni Lakiṣi, nwọn si pa a nibẹ.
20 Nwọn si gbé e wá lori ẹṣin: a si sin
i ni Jerusalemu pẹlu awọn baba rẹ̀ ni ilu
Dafidi.
21 Gbogbo awọn enia Juda si mu Asa-
riah ẹni ọdun mẹrindilogun, nwọn si fi i
jọba ni ipò Amasiah baba rẹ̀.
22 On si kọ́ Elati, o si mu u pada fun
Juda, lẹhin ti ọba sùn pẹlu awọn baba rẹ̀.
23 Li ọdun kẽdogun Amasiah ọmọ Joaṣi
ọba Juda, Jeroboamu ọmọ Joaṣi ọba Israeli
bẹ̀rẹ si ijọba ni Samaria, o si jọba li ọdun
mọkanlelogoji.
24 O si ṣe buburu li oju Oluwa: kò yà
kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ Jeroboamu ọmọ Ne-
bati, ẹniti o mu Israeli ṣẹ̀.
25 O si tun mu agbègbe ilẹ Israeli pada
lati atiwọ̀ Hamati titi de okun pẹ̀tẹlẹ, gẹgẹ
bi ọ̀rọ Oluwa Ọlọrun Israeli, ti o ti sọ nipa
ọwọ iranṣẹ rẹ̀ Jona woli, ọmọ Amittai, ti
Gat-heferi.
26 Nitori Oluwa ri ipọnju Israeli pe, o
korò gidigidi: nitori kò si ọmọ-ọdọ, tabi
omnira tabi olurànlọwọ kan fun Israeli.
27 Oluwa kò si wipe on o pa orukọ
Israeli rẹ̀ labẹ ọrun: ṣugbọn o gbà wọn
nipa ọwọ Jeroboamu ọmọ Joaṣi.
28 Ati iyokù iṣe Jeroboamu ati gbogbo
eyiti o ṣe, ati agbara rẹ̀, bi o ti jagun si, ati
bi o ti gbà Damasku, ati Hamati, ti iṣe ti
Juda, pada fun Israeli, a kò ha kọ wọn
sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Israeli?
29 Jeroboamu si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀,

Digitized by Google

ẹlu awọn ọba Israeli ; Sakariah ọmọ
ọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 15.

ọkun kẹtadilọgbọ̀n Jeroboamu ọba
.sraeli ni Asariah (Ussiah) ọmọ Ama-
ọba Juda bẹ̀rẹ si ijọba.
Ẹni ọdun mẹrindilogun li on iṣe ni-
o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun mejilelã-
ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ a ma jẹ
iah ti Jerusalemu.
O si ṣe eyiti o tọ loju Oluwa, gẹgẹ bi
ọo eyiti baba rẹ̀ Amasiah ti ṣe ;
Kiki ibi giga wọnni ni a kò mu kuro :
enia nrubọ, nwọn si nsun turari sibẹ
giga wọnni.
Oluwa si kọlù ọba na, bẹ̃li o di adẹtẹ̀
li ọjọ ikú rẹ̀, o si ngbe ile ihámọ :
nu ọmọ ọba si wà lori ile na, o nṣe
awọn enia ilẹ na.
Ati iyokù iṣe Asariah, ati ohun gbo-
ti o ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
wọn ọba Juda ?
Asariah si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀ ;
a si sìn i pẹlu awọn baba rẹ̀, ni ilu
di : Jotamu ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
Li ọdun kejidilogoji Asariah ọba Juda
akariah ọmọ Jeroboamu jọba lori Isra-
i Samaria li oṣù mẹfa.
O si ṣe eyi ti o buru li oju Oluwa, bi
a baba rẹ̀ ti ṣe : on kò kuro ninu ẹ̀ṣẹ
boamu ọmọ Nebati, ẹniti o mu Israeli

O Ṣallumu ọmọ Jabeṣi si dì rikiṣi si i,
kọlù u niwaju awọn enia, o si pa a, o
ọba ni ipò rẹ̀.
1 Ati iyokù iṣe Sakariah, kiyesi i, a kọ
a sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Israeli.
2 Eyi li ọ̀rọ Oluwa ti o ti sọ fun Jehu
e, Awọn ọmọ rẹ iran kẹrin yio joko lori
Israeli, bẹ̃li o si ri.
3 Ṣallumu ọmọ Jabeṣi bẹ̀rẹ si ijọba li
n kọkandilogoji Ussiah ọba Juda ; o si
a oṣù kan gbáko ni Samaria.
14 Nitoriti Menahemu ọmọ Gadi gòke
i Tirsa lọ, o si wá si Samaria, o si kọlù
llumu ọmọ Jabeṣi ni Samaria, o si pa a,
i jọba ni ipò rẹ̀.
15 Ati iyokù iṣe Ṣallumu, ati rikiṣi rẹ̀
o dì, kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ
ọn ọba Israeli.
16 Nigbana ni Menahemu kọlù Tifsa,
i ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀, ati ilẹ
bègbe rẹ̀ wọnni lati Tifsa lọ : nitoriti
vọn kò ṣi i silẹ fun u, nitorina li o ṣe kọlù
u ; ati gbogbo awọn obirin aboyun inu rẹ̀
li o là ni inu.
17 Li ọdun kọkandilogoji Asariah ọba
Juda ni Menahemu ọmọ Gadi bẹ̀rẹ si ijọba
lori Israeli, o si jọba ọdun mẹwa ni Sama-
ria.
18 O si ṣe eyi ti o buru li oju Oluwa :
on kò si lọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ Jeroboamu ọmọ
Nebati ẹniti o mu Israeli ṣẹ̀, li ọjọ rẹ̀
gbogbo.
19 Fulu ọba Assiria si gbé ogun tì ilẹ
na : Menahemu si fi ẹgbẹrin talenti fadakà
fun Fulu, ki ọwọ rẹ̀ ki o le pẹlu on lati fi
idi ijọba na mulẹ lọwọ rẹ̀.
20 Menahemu si fi agbara gbà owo na
lọwọ Israeli, ani lọwọ gbogbo awọn ọlọrọ̀,
ãdọta ṣekeli fadakà lọwọ olukuluku enia,
lati fi fun ọba Assiria. Bẹ̃ni ọba Assiria
yipada, kò si duro ni ilẹ na.
21 Ati iyokù iṣe Menahemu, ati gbogbo
eyiti o ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ
awọn ọba Israeli ?
22 Menahemu si sùn pẹlu awọn baba
rẹ̀ ; Pekahiah ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
23 Ni ãdọta ọdun Asariah ọba Juda,
Pekahiah ọmọ Menahemu bẹ̀rẹ si ijọba lori
Israeli ni Samaria, o si jọba ọdun meji.
24 O si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa : on
kò si lọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ Jeroboamu ọmọ
Nebati, ẹniti o mu Israeli ṣẹ̀.
25 Ṣugbọn Peka ọmọ Remaliah, olori-
ogun rẹ̀, dì rikiṣi si i, o si kọlù u ni Sama-
ria, li odi ile ọba, pẹlu Argobu, ati Arie,
ati ãdọta enia ninu awọn ọmọ Gileadi pẹlu
rẹ̀ : o si pa a, o si jọba ni ipò rẹ̀.
26 Ati iyokù iṣe Pekahiah, ati gbogbo
eyiti o ṣe, kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ
ọjọ awọn ọba Israeli.
27 Li ọdun kejilelãdọta Asariah ọba
Juda ni Peka ọmọ Remaliah bẹ̀rẹ si ijọba
lori Israeli ni Samaria, o si jọba li ogun
ọdun.
28 O si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa : on
kò lọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ Jeroboamu ọmọ Neba-
ti, ẹniti o mu Israeli ṣẹ̀.
29 Li ọjọ Peka ọba Israeli ni Tiglat-
pileseri ọba Assiria de, o si kó Ijoni, ati
Abel-betmaaka, ati Janoa, ati Kedeṣi, ati
Hasori, ati Gileadi, ati Galili, gbogbo ilẹ
Naftali, o si kó wọn ni igbèkun lọ si
Assiria.
30 Hoṣea ọmọ Ela si dì rikiṣi si Peka
ọmọ Remaliah, o si kọlù u, o si pa a, o si
jọba ni ipò rẹ̀, li ogun ọdun Jotamu ọmọ
Ussiah.
31 Ati iyokù iṣe Peka, ati gbogbo eyiti

Digitized by Google

o ṣe, kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ
awọn ọba Israeli.
32 Li ọdun keji Peka ọmọ Remaliah ọba
Israeli, ni Jotamu ọmọ Ussiah ọba Juda
bẹ̀rẹ si ijọba.
33 Ẹni ọdun mẹ̃dọgbọ̀n ni, nigbati o
bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun mẹrindilogun
ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ ni Jeruṣa,
ọmọbirin Sadoku.
34 O si ṣe eyiti o tọ́ li loju Oluwa: o si
ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti Ussiah baba rẹ̀ ti
ṣe.
35 Ṣugbọn a kò mu ibi giga wọnni kuro:
awọn enia nrubọ, nwọn si nsun turari sibẹ
ni ibi giga wọnni. On kọ́ ẹnu-ọ̀na giga ile
Oluwa.
36 Ati iyokù iṣe Jotamu, ati gbogbo
eyiti o ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ
awọn ọba Juda?
37 Li ọjọ wọnni Oluwa bẹ̀rẹ si irán Re-
sini ọba Siria, ati Peka ọmọ Remaliah si
Juda.
38 Jotamu si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a
si sìn i pẹlu awọn baba rẹ̀, ni ilu Dafidi
baba rẹ̀, Ahasi ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 16.

LI ọdun kẹtadilogun Peka ọmọ Rema-
liah, Ahasi ọmọ Jotamu ọba Juda bẹ̀rẹ
si ijọba.
2 Ẹni ogún ọdun ni Ahasi nigbati o bẹ̀rẹ
si ijọba, o si jọba ọdun mẹrindilogun ni Je-
rusalemu, kò si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa
Ọlọrun rẹ̀, gẹgẹ bi Dafidi baba rẹ̀.
3 Ṣugbọn o rìn li ọ̀na awọn ọba Israeli,
nitõtọ, o si mu ki ọmọ rẹ̀ ki o kọja lãrin
iná pẹlu, gẹgẹ bi iṣe irira awọn keferi, ti
Oluwa le jade niwaju awọn ọmọ Israeli.
4 O si rubọ, o si sun turari ni ibi giga
wọnni, ati lori awọn òke kekeke, ati labẹ
gbogbo igi tutù.
5 Nigbana ni Resini ọba Siria ati Peka
ọmọ Remaliah ọba Israeli gòke wá si Jeru-
salemu lati jagun: nwọn si do tì Ahasi,
ṣugbọn nwọn kò le bori rẹ̀.
6 Li akokò na, Resini ọba Siria gbà
Elati pada fun Siria, o si lé awọn enia
Juda kuro ni Elati: awọn ara Siria si wá
si Elati, nwọn si ngbe ibẹ titi di oni yi.
7 Ahasi si rán onṣẹ si ọdọ Tiglat-pileseri
ọba Assiria wipe, Iranṣẹ rẹ li emi, ati ọmọ
rẹ; gòke wá, ki o si gbà mi lọwọ ọba Siria,
ati lọwọ ọba Israeli, ti o dide si mi.
8 Ahasi si mu fadakà ati wura ti a ri ni
ile Oluwa, ati ninu iṣura ile ọba, o si rán a
li ọrẹ si ọba Assiria.
9 Ọba Assiria si gbọ́ tirẹ̀: nitoriti ọba
Assiria gòke wá si Damasku, o si kó o, o si
mu u ni igbèkun lọ si Kiri, o si pa Resini.
10 Ahasi ọba si lọ si Damasku lati pade
Tiglat-pileseri, ọba Assiria, o si ri pẹpẹ kan
ti o wà ni Damasku: Ahasi ọba si rán
awòran pẹpẹ na, ati apẹrẹ rẹ̀ si Urijah
alufa, gẹgẹ bi gbogbo iṣẹ ọnà rẹ̀.
11 Urijah alufa si ṣe pẹpẹ kan gẹgẹ bi
gbogbo eyiti Ahasi ọba fi ranṣẹ si i lati
Damasku wá; bẹ̃ni Urijah alufa ṣe e de
atibọ̀ Ahasi ọba lati Damasku wá.
12 Nigbati ọba si ti Damasku de, ọba si
ri pẹpẹ na: ọba si sunmọ pẹpẹ na, o si
rubọ lori rẹ̀.
13 O si sun ẹbọ ọrẹ-sisun rẹ̀ ati ọrẹ-jijẹ
rẹ̀, o si ta ohun-mimu rẹ̀ silẹ, o si wọ́n ẹ̀jẹ
ọrẹ-alafia rẹ̀ si ara pẹpẹ na.
14 Ṣugbọn o mu pẹpẹ idẹ ti o wà niwaju
Oluwa kuro lati iwaju ile na, lati agbede-
meji pẹpẹ na, ati ile Oluwa, o si fi i si apa
ariwa pẹpẹ na.
15 Ahasi ọba si paṣẹ fun Urijah alufa,
wipe, Lori pẹpẹ nla ni ki o mã sun ọrẹ-
sisun orowurọ̀ ati ọrẹ-jijẹ alalẹ, ati ẹbọ-
sisun ti ọba, ati ọrẹ-jijẹ rẹ̀, pẹlu ọrẹ-sisun
ti gbogbo awọn enia ilẹ na, ati ọrẹ-jijẹ
wọn, ati ọrẹ ohun-mimu wọn; ki o si
wọ́n gbogbo ẹ̀jẹ ọrẹ-sisun na lori rẹ̀, ati
gbogbo ẹ̀jẹ ẹbọ miran: ṣugbọn niti pẹpẹ
idẹ na emi o mã gbero ohun ti emi o fi i
ṣe.
16 Bayi ni Urijah alufa ṣe, gẹgẹ bi
gbogbo eyiti Ahasi ọba pa li aṣẹ.
17 Ahasi ọba si ké alafo ọnà arin awọn
ijoko na, o si ṣi agbada na kuro lara wọn;
o si gbé agbada-nla na kalẹ kuro lara awọn
malu idẹ ti mbẹ labẹ rẹ̀, o si gbé e kà ilẹ ti
a fi okuta tẹ́.
18 Ibi ãbò fun ọjọ isimi ti a kọ́ ninu ile
na, ati ọ̀na ijade si ode ti ọba, ni o yipada
kuro ni ile Oluwa nitori ọba Assiria.
19 Ati iyokù iṣe Ahasi ti o ṣe, a kò ha
kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Juda?
20 Ahasi si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a si
sìn i pẹlu awọn baba rẹ̀ ni ilu Dafidi: He-
sekiah ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 17.

LI ọdun kejila Ahasi ọba Juda ni Hoṣea
ọmọ Ela bẹrẹ si ijọba ni Samaria, lori
Israeli li ọdun mẹsan.
2 O si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa, ṣu-
gbọn kì iṣe bi awọn ọba Israeli ti o ti wà
ṣãju rẹ̀.
3 On ni Ṣalamaneseri ọba Assiria gòke

Digitized by Google

; Hoṣea si di iranṣẹ rẹ̀, o si ta a li

ba Assiria si ri ọ̀tẹ ninu Hoṣea : ni-
o ti rán onṣẹ sọdọ So ọba Egipti, kò
ọrẹ fun ọba Assiria wá bi iti mã iṣe
dun ; nitorina ni ọba Assiria há a mọ,
è e ni ile tubu.
Nigbana ni ọba Assiria gòke wá si
o ilẹ na, o si gòke lọ si Samaria, o si
li ọ̀dun mẹta.
Li ọdun kẹsan Hoṣea, ni ọba Assiria
amaria, o si kó Israeli lọ si Assiria, o
vọn si Hala ati si Habori, leti odò Go-
ati si ilu awọn ara Media.
O si ṣe, nitoriti awọn ọmọ Israeli dẹṣẹ
awa Ọlọrun wọn, ti o ti mu wọn gòke
ẹ Egipti wá, kuro labẹ ọwọ Farao ọba
ti, ti nwọn si mbẹ̀ru ọlọrun miran.
Ti nwọn si nrìn ninu ilana awọn ke-
ti Oluwa ti le jade kuro niwaju awọn
Israeli, ati ti awọn ọba Israeli, ti nwọn

Awọn ọmọ Israeli si ṣe ohun ikọ̀kọ ti
ọ́ si Oluwa Ọlọrun wọn, nwọn si kọ̀
giga fun ara wọn ni gbogbo ilu wọn,
ile-iṣọ awọn olùṣọ titi de ilu olodi.
Nwọn si gbé awọn ere kalẹ, nwọn
ere oriṣa si lori òke giga gbogbo, ati
igi tutu gbogbo :
Nibẹ ni nwọn si sun turari ni gbogbo
giga wọnni, bi awọn keferi ti Oluwa kó
iwaju wọn ti ṣe ; nwọn si ṣe ohun bu-
uru lati rú ibinu Oluwa soke.
2 Nitoriti nwọn sìn oriṣa wọnni, eyiti
wa ti wi fun wọn pe, Ẹnyin kò gbọdọ
kan yi.
3 Sibẹ Oluwa jẹri si Israeli, ati si Juda,
a ọwọ gbogbo awọn woli, ati gbogbo
n ariran, wipe, Ẹ yipada kuro ninu ọ̀na
uru nyin, ki ẹ si pa ofin mi ati ilana mi
gẹgẹ bi gbogbo ofin ti mo pa li aṣẹ
awọn baba nyin, ti mo rán si nyin nipa
awọn woli iranṣẹ mi.
4 Sibẹ nwọn kò fẹ igbọ́, ṣugbọn nwọn
ọrùn wọn le, gẹgẹ bi ọrùn awọn baba
, ti kò gbà Oluwa Ọlọrun wọn gbọ́.
5 Nwọn si kọ̀ ilana rẹ̀, ati majẹmu rẹ̀
, ti o ba awọn baba wọn dá, ati ẹri rẹ̀ ti
si wọn : nwọn si ntọ̀ ohun asan lẹhin,
ọn si huwa asan, nwọn si ntọ̀ awọn ke-
lẹhin ti o yi wọn ka, niti ẹniti Oluwa
ilọ fun wọn pe, ki nwọn ki o máṣe ṣe
awọn.
16 Nwọn si kọ̀ gbogbo ofin Oluwa Ọlọ-
n wọn silẹ, nwọn si ṣe ere didà fun ara
n, ani, ẹgbọ̀rọ malu meji, nwọn si ṣe
ere oriṣa, nwọn si mbọ gbogbo ogun ọrun,
nwọn si sin Baali.
17 Nwọn si mu ki awọn ọmọkọnrin,
wọn ati ọmọbirin wọn ki o kọja lãrin iná,
nwọn si nfọ̀ afọ̀ṣẹ, nwọn si nṣe alupayida,
nwọn si tà ara wọn lati ṣe ibi niwaju Olu-
wa, lati mu u binu.
18 Nitorina ni Oluwa ṣe binu si Israeli
gidigidi, o si mu wọn kuro niwaju rẹ̀ : ọkan
kò kù bikòṣe ẹ̀ya Juda nikanṣoṣo.
19 Juda pẹlu kò pa aṣẹ Oluwa Ọlọrun
wọn mọ́, ṣugbọn nwọn rìn ninu ilana Israeli
ti nwọn ṣe.
20 Oluwa si kọ̀ gbogbo iru-ọmọ Israeli
silẹ, o si wahala wọn o si fi wọn le awọn
akoni lọwọ, titi o si fi ta wọn nù kuro ni-
waju rẹ̀.
21 Nitori ti o yà Israeli kuro ni idile
Dafidi ; nwọn si fi Jeroboamu ọmọ Nebati
jọba : Jeroboamu si tì Israeli kuro lati má
tọ̀ Oluwa lẹhin, o si mu wọn ṣẹ̀ ẹ̀ṣẹ nla.
22 Nitoriti awọn ọmọ Israeli rìn ninu
gbogbo ẹ̀ṣẹ Jeroboamu ti o ṣẹ̀ ; nwọn kò lọ
kuro ninu wọn ;
23 Titi Oluwa fi mu Israeli kuro niwaju
rẹ̀, bi o ti sọ nipa gbogbo awọn woli iranṣẹ
rẹ̀. Bẽli a kó Israeli kuro ni ilẹ wọn lọ si
Assiria, titi di oni yi.
24 Ọba Assiria si kó enia lati Babeli wá,
ati lati Kuta, ati lati Afa, ati lati Hamati,
ati lati Sefarfaimi, o si fi wọn sinu ilu
Samaria wọnni, ni ipò awọn ọmọ Israeli ;
nwọn si ni Samaria, nwọn si ngbe inu rẹ̀
wọnni.
25 O si ṣe li atètekọ-gbé ibẹ wọn, nwọn
kò bẹ̀ru Oluwa : nitorina ni Oluwa ṣe rán
awọn kiniun sãrin wọn, ti o pa ninu
wọn.
26 Nitorina ni nwọn ṣe sọ fun ọba As-
siria wipe, Awọn orilẹ-ède ti iwọ ṣi kuro,
ti o si fi sinu ilu Samaria wọnni, kò mọ̀
iṣe Ọlọrun ilẹ na : nitorina li on ṣe rán
awọn kiniun sãrin wọn, si kiyesi i, nwọn
pa wọn, nitoriti nwọn kò mọ̀ iṣe Ọlọrun
ilẹ na.
27 Nigbana li ọba Assiria paṣẹ, wipe, Ẹ
mu ọkan ninu awọn alufa ti ẹnyin ti kó ti
ọhún wá lọ sibẹ ; ẹ si jẹ ki wọn ki o lọ
igbe ibẹ, ki ẹ si jẹ ki o ma kọ́ wọn ni iṣe
Ọlọrun ilẹ na.
28 Nigbana ni ọkan ninu awọn alufa ti
nwọn ti kó ti Samaria lọ, wá, o si joko ni
Beteli, o si kọ́ wọn bi nwọn o ti mã bẹ̀ru
Oluwa.
29 Ṣugbọn olukuluku orilẹ-ède ṣe oriṣa
tirẹ̀, nwọn si fi wọn sinu ile ibi giga wọnni



Digitized by Google

ti awọn ara Samaria ti ṣe, olukuluku orilẹ-ède ninu ilu ti nwọn ngbe.
30 Awọn enia Babeli ṣe agọ awọn wundia, ati awọn enia Kuti ṣe oriṣa Nergali, ati awọn enia Hamati ṣe ti Aṣima,
31 Ati awọn ara Afa ṣe ti Nibhasi ati ti Tartaki, ati awọn ara Sefarfaimu sun awọn ọmọ wọn ninu iná fun Adrammeleki ati Anammeleki awọn òriṣa Sefarfaimu.
32 Nwọn bẹru Oluwa pẹlu, nwọn si ṣe alufa ibi giga wọnni fun ara wọn, ninu awọn enia lasan, ti nrubọ fun wọn ni ile ibi giga wọnni.
33 Nwọn bẹru Oluwa, nwọn si nsìn oriṣa wọn gẹgẹ bi iṣe awọn orilẹ-ède, ti nwọn kó lati ibẹ lọ.
34 Titi di oni yi nwọn nṣe bi iṣe wọn atijọ: nwọn kò bẹru Oluwa, bẽni nwọn kò ṣe bi idasilẹ wọn, tabi ilàna wọn, tabi ofin ati aṣẹ ti Oluwa pa fun awọn ọmọ Jakobu, ti o sọ ni Israeli;
35 Awọn ẹniti Oluwa ti ba dá majẹmu, ti o si ti kilọ fun wọn, wipe, Ẹnyin kò gbọdọ bẹru awọn ọlọrun miran, bẽni ẹnyin kò gbọdọ tẹ ara nyin ba fun wọn, tabi ki ẹ sìn wọn, tabi ki ẹ rubọ si wọn:
36 Ṣugbọn Oluwa ti o mu nyin gòke ti ilẹ Egipti wá, pẹlu agbara nla ati ninà apá, on ni ki ẹ mã bẹru, on ni ki ẹ si mã tẹriba fun, on ni ki ẹ sì mã rubọ si.
37 Ati idasilẹ wọnni, ati ilàna wọnni, ati ofin ati aṣẹ ti o ti kọ fun nyin, li ẹnyin o mã kiyesi lati mã ṣe li ọjọ gbogbo; ẹnyin kò si gbọdọ bẹru awọn ọlọrun miràn.
38 Ati majẹmu ti mo ti ba nyin dá ni ẹnyin kò gbọdọ gbàgbe; bẽni ẹnyin kò gbọdọ bẹru awọn ọlọrun miran.
39 Ṣugbọn Oluwa Ọlọrun nyin ni ẹnyin o mã bẹru; on ni yio si gbà nyin lọwọ awọn ọta nyin gbogbo.
40 Nwọn kò si gbọ́, ṣugbọn nwọn ṣe bi iṣe wọn atijọ.
41 Bẽli awọn orilẹ-ède wọnyi bẹru Oluwa, nwọn si sìn awọn ere fifin wọn pẹlu; awọn ọmọ wọn, ati awọn ọmọ-ọmọ wọn, bi awọn baba wọn ti ṣe, bẽli awọn na nṣe titi fi di oni yi.

## ORI 18.

O SI ṣe li ọdun kẹta Hoṣea ọmọ Ela ọba Israeli ni Hesekiah ọmọ Ahasi ọba Juda bẹrẹ si ijọba.
2 Ẹni ọdun mẽdọgbọn li on nigbati o bẹrẹ si ijọba; o si jọba li ọdun mọkandilọgbọn ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ ni Abi ọmọbirin Sakariah.
3 O si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa, gẹgẹ bi gbogbo eyiti Dafidi baba rẹ ti ṣe.
4 On mu ibi giga wọnni kuro, o si fọ́ awọn ere, o si wó awọn ere oriṣa lulẹ, o si fọ́ ejò idẹ na tútu ti Mose ti ṣe: nitori titi di ọjọ wọnni, awọn ọmọ Israeli nsun turari si i: a si pè e ni Nehuṣtani.
5 O gbẹkẹle Oluwa Ọlọrun Israeli; ati lẹhin rẹ̀ kò si ẹniti o dabi rẹ̀ ninu gbogbo awọn ọba Juda, bẽni ṣãju rẹ̀ kò si ẹnikan.
6 Nitoriti o faramọ Oluwa, kò si lọ kuro lẹhin rẹ, ṣugbọn o pa ofin rẹ̀ wọnni mọ, ti Oluwa ti pa li aṣẹ fun Mose.
7 Oluwa si wà pẹlu rẹ̀; o si ṣe rere nibikibi ti o ba jade lọ: o si ṣọtẹ si ọba Assiria, kò si sìn i mọ.
8 On kọlù awọn ara Filistia, ani titi de Gasa, ati agbègbe rẹ̀, lati ile iṣọ awọn olùṣọ titi de ilu olodi.
9 O si ṣe li ọdun kẹrin Hesekiah ọba, ti iṣe ọdun keje Hoṣea ọmọ Ela ọba Israeli, ni Ṣalmaneseri ọba Assiria gòke wá si Samaria, o si dotì i.
10 Lẹhin ọdun mẹta nwọn kó o; ani li ọdun kẹfa Hesekiah, eyini ni ọdun kẹsan Hoṣea ọba Israeli li a kó Samaria.
11 Ọba Assiria si kó Israeli lọ si Assiria, o si fi wọn si Hala ati si Habori leti odò Gosani, ati si ilẹ awọn ara Media wọnni:
12 Nitoriti nwọn kò gbà ohùn Oluwa Ọlọrun wọn gbọ́, ṣugbọn nwọn dà majẹmu rẹ̀, ati ohun gbogbo ti Mose iranṣẹ Oluwa pa li aṣẹ, nwọn kò si fi eti si wọn, bẽni nwọn kò si ṣe wọn.
13 Li ọdun 'kẹrinla Hesekiah ọba, ni Sennakeribu ọba Assiria goke wá si gbogbo awọn ilu olodi Juda, o si kó wọn.
14 Hesekiah ọba Juda si ranṣẹ si ọba Assiria ni Lakiṣi, wipe, Mo ti ṣẹ̀; padà lẹhin mi: eyiti iwọ ba bù fun mi li emi o rù. Ọba Assiria si bù ọ̃dunrun talenti fadakà, ati ọgbọn talenti wura fun Hesekiah ọba Juda.
15 Hesekiah si fun u ni gbogbo fadakà ti a ri ni ile Oluwa, ati ninu iṣura ile ọba.
16 Li akòko na ni Hesekiah ké gbogbo wura kuro lara awọn ilẹkun ile Oluwa, ati kuro lara ọwọ̀n wọnni ti Hesekiah ọba Juda ti fi wura bò, o si fi wọn fun ọba Assiria.
17 Ọba Assiria si rán Tartani, ati Rabsarisi, ati Rabṣake, lati Lakiṣi lọ si ọdọ Hesekiah ọba pẹlu ogun nla si Jerusalemu. Nwọn si gòke wá, nwọn si de Jerusalemu. Nwọn si gòke wá, nwọn de, nwọn si duro

Digitized by Google

ti idari omi abàta òke, ti mbẹ li eti òpopo
pa afọṣọ.
18 Nigbati nwọn si ké si ọba, Eliakimu
ọ Hilkiah ti iṣe olori ile na si jade tọ̀
ọn wá, ati Ṣebna akọwe, ati Joa ọmọ
afu akọwe-iranti.
19 Rabṣake si wi fun wọn pe, Ẹ sọ fun
esekiah nisisiyi pe, Bayi ni ọba nla, ọba
ssiria wi pe, Kini igbẹkẹle yi ti iwọ
ẹkẹle ?
20 Iwọ wipe (ṣugbọn ọ̀rọ ète lasan ni
ọn), emi ni ìmọ ati agbara lati jagun.
ẹ tani iwọ gbẹkẹle, ti iwọ fi ṣọ̀tẹ si
?
21 Kiyesi i, nisisiyi, iwọ gbẹkẹle ọ̀pa
 fifọ yi, ani le Egipti, lara ẹniti bi ẹnikan
fi ara tì, yio wọ̀ ọ li ọwọ lọ, yio si gun
bẹ̃ni Farao ọba Egipti ri fun gbogbo
ọn ti o gbẹkẹ wọn le e.
22 Ṣugbọn bi ẹnyin ba wi fun mi pe,
a gbẹkẹle Oluwa Ọlọrun wa: on ha kọ
ẹniti Hesekiah ti mu awọn ibi giga rẹ̀,
awọn pẹpẹ rẹ̀ kuro, ti o si wi fun Juda
Jerusalemu pe, Ẹnyin o ma sìn niwaju
pẹ yi ni Jerusalemu ?
23 Njẹ nisisiyi, Mo bẹ̀ ọ, ba oluwa mi
a Assiria ṣe adehun, emi o si fun ọ li
bã ẹṣin, bi iwọ nipa tirẹ ba lè ni enia to
i gun wọn.
24 Njẹ bawo ni iwọ o ha ti ṣe le yi oju
logun kan ti o kere jùlọ pada ninu awọn
nṣẹ oluwa mi, ti iwọ si gbẹkẹ rẹ le
ipti fun kẹkẹ́ ati fun ẹlẹṣin ?
25 Emi ha dẹhin Oluwa gòke wá nisisiyi
ibi yi lati pa a run ? Oluwa wi fun mi
, Gòke lọ si ilẹ yi, ki o si pa a run.
26 Nigbana ni Eliakimu ọmọ Hilkiah,
Ṣebna, ati Joa wi fun Rabṣake pe, Emi
ọ, ba nwọn iranṣẹ rẹ sọ̀rọ li ède Siria;
oriti awa gbọ́ ọ: ki o má si ṣe ba wa
ọ li ède Juda li leti awọn enia ti mbẹ
i odi.
27 Ṣugbọn Rabṣake sọ fun wọn pe, Oluwa
ha rán mi si oluwa rẹ, ati si ọ, lati sọ
wọnyi bi ? kò ṣepe awọn ọkọnrin ti o
o lori odi li o rán mi si, ki nwọn ki o
jẹ igbẹ́ ara wọn, ati ki nwọn ki o le mu
ara wọn pẹlu nyin ?
28 Nigbana ni Rabṣake duro, o si kigbe
ohùn rara li ède Juda o si sọ wipe, Ẹ
ọ̀rọ ọba nla, ọba Assiria:
29 Bayi li ọba wi pe, Ẹ máṣe jẹ ki
sekiah tàn nyin jẹ: nitori kì yio le gbà
in kuro lọwọ rẹ̀:
30 Ẹ máṣe jẹ ki Hesekiah mu nyin gbẹ-
e Oluwa, wipe, Ni gbigbà Oluwa yio
gbà wa, a kì yio si fi ilu yi le ọba Assiria
lọwọ.
31 Ẹ máṣe fi eti si ti Hesekiah: nitori
bayi li ọba Assiria wi pe, Fi ẹbùn wá oju
rere mi, ki ẹ si jade tọ̀ mi wá, ki olukuluku
nyin ki o si mã jẹ ninu àjarà rẹ̀, ati oluku-
luku ninu igi ọ̀pọtọ rẹ̀, ki olukuluku nyin
ki o si mu omi ninu àmu rẹ̀:
32 Titi emi o fi wá mu nyin kuro lọ si
ilẹ bi ti ẹnyin tikara nyin, si ilẹ ọkà ati
ọti-waini, ilẹ onjẹ ati ọgbà ajara, ilẹ ororo
olifi ati ti oyin, ki ẹnyin ki o le yè, ki ẹ
má ba kú: ki ẹ má si fi eti si ti Hesekiah,
nigbati o ba ntàn nyin wipe, Oluwa yio
gbà wa.
33 Ọkan ninu awọn oriṣa awọn orilẹ-
ède ti igbà ilẹ rẹ̀ kuro lọwọ ọba Assiria ri
bi ?
34 Nibo li awọn oriṣa Hamati, ati Ar-
padi gbe wà ? Nibo li awọn oriṣa Sefar-
faimu, Hena, ati Ifa gbe wà ? Nwọn ha
gbà Samaria kuro lọwọ mi bi ?
35 Tani ninu gbogbo awọn oriṣa ilẹ
wọnni ti o gbà ilẹ wọn kuro lọwọ mi, ti
Oluwa yio fi gbà Jerusalemu kuro lọwọ mi ?
36 Ṣugbọn awọn enia pa ẹnu wọn mọ́,
nwọn kò si da a li ohùn ọ̀rọ kan: nitori
aṣẹ ọba ni, pe, Ẹ máṣe da a li ohùn.
37 Nigbana ni Eliakimu ọmọ Hilkiah ti
iṣe olori ile, ati Ṣebna akọwe, ati Joa ọmọ
Asafu akọwe-iranti wá sọdọ Hesekiah, ti
awọn ti aṣọ wọn ni fifàya, nwọn si sọ ọ̀rọ
Rabṣake fun u.

## ORI 19.

O SI ṣe, nigbati Hesekiah ọba gbọ́, o si fà
aṣọ rẹ̀ ya, o si fi aṣọ ọ̀fọ bò ara rẹ̀, o si
lọ sinu ile Oluwa.
2 O si rán Eliakimu, ti iṣe olori ile, ati
Ṣebna akọwe, ati awọn àgba alufa, ti nwọn
fi aṣọ ọ̀fọ bò ara, sọdọ Isaiah woli ọmọ
Amosi.
3 Nwọn si wi fun u pe, Bayi ni Hese-
kiah wi, Ọjọ oni ọjọ wàhala ni, ati ti ibawi,
ati ẹgàn: nitoriti awọn ọmọ de oju-ibí, kò
si si agbara lati bi.
4 Boya Oluwa Ọlọrun rẹ yio gbọ́ gbo-
gbo ọ̀rọ Rabṣake ẹniti ọba Assiria oluwa
rẹ̀ ti rán lati kẹgàn Ọlọrun alãyè, yio si ba
a wi nitori ọ̀rọ ti Oluwa Ọlọrun rẹ ti gbọ́:
njẹ nitorina, gbé adura rẹ soke fun awọn
iyokù ti o kù.
5 Bẹ̃li awọn iranṣẹ Hesekiah ọba wá
sọdọ Isaiah.
6 Isaiah si wi fun wọn pe, Bayi ni ki ẹ

sọ fun oluwa nyin, Bayi li Oluwa wi pe,
Máṣe bẹ̀ru ọ̀rọ wọnni, ti o ti gbọ́, ti awọn
iranṣẹ ọba Assiria fi sọ ọ̀rọ odi si mi.
7 Kiyesi i, emi o rán ẽmi kan si i, on o
si gbọ́ ariwo, yio si pada si ilẹ on tikalarẹ̀;
emi o si mu u ti ipa idà ṣubu ni ilẹ on
tikalarẹ̀.
8 Bẹ̃ni Rabṣake pada, o si ba ọba Assiria
mba Libna jagun: nitoriti o ti gbọ́ pe o ti
lọ kuro ni Lakiṣi.
9 Nigbati o si gburo Tirhaka ọba Eti-
opia, pe, Kiyesi i, o jade wá lati ba ọ jagun;
o si tun rán awọn onṣẹ si ọdọ Hesekiah
wipe,
10 Bayi li ẹnyin o sọ fun Hesekiah ọba
Juda, wipe, Máṣe jẹ ki Ọlọrun rẹ, ẹniti iwọ
gbẹkẹle ki o tàn ọ jẹ, wipe, A kì yio fi
Jerusalemu le ọwọ ọba Assiria.
11 Kiyesi i, iwọ ti gbọ́ ohun ti awọn
ọba Assiria ti ṣe si gbogbo ilẹ, ni pipa wọn
run patapata: a o ha si gbà iwọ bi?
12 Oriṣa awọn orilẹ-ède ha gbà awọn ti
awọn baba mi ti parun; bi Gosani, ati
Harani, ati Rescfu, ati awọn ọmọ Edeni ti
o wà ni Telassari?
13 Nibo li ọba Hamati, ati ọba Arpadi,
ati ọba ilu Sefarfaimu, ti Hena, ati Ifa gbe
wà?
14 Hesekiah si gbà iwe na lọwọ awọn
onṣẹ na, o si kà a: Hesekiah si gòke lọ sinu
ile Oluwa, o si tẹ́ ẹ siwaju Oluwa.
15 Hesekiah si gbadura niwaju Oluwa, o
si wipe: Oluwa Ọlọrun Israeli, ti ngbe
ãrin awọn kerubu, iwọ li Ọlọrun, ani iwọ
nikanṣoṣo, ninu gbogbo awọn ilẹ-ọba aiye;
iwọ li o dá ọrun on aiye.
16 Deti rẹ silẹ Oluwa, ki o si gbọ́; ṣi
oju rẹ, Oluwa, ki o si wò: ki o si gbọ́ ọ̀rọ
Sennakeribu ti o rán lati kẹgàn Ọlọrun
alãyè.
17 Lõtọ ni, Oluwa, awọn ọba Assiria ti
pa awọn orilẹ-ède run ati ilẹ wọn.
18 Nwọn si ti gbe òriṣa wọn sọ sinu iná;
nitoriti nwọn kì iṣe ọlọrun, bikòṣe iṣẹ ọwọ
enia, igi ati okuta: nitorina ni nwọn ṣe pa
wọn run.
19 Njẹ nitorina, Oluwa Ọlọrun wa, emi
mbẹ̀ o, gbà wa lọwọ rẹ̀, ki gbogbo ilẹ ọba
aiye le mọ̀ pe iwọ Oluwa iwọ li Ọlọrun
nikanṣoṣo.
20 Nigbana ni Isaiah ọmọ Amosi ranṣẹ
si Hesekiah wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun
Israeli wi pe, adura ti iwọ ti gbà si mi si
Sennakeribu ọba Assiria emi ti gbọ́.
21 Eyi li ọ̀rọ ti Oluwa ti sọ niti rẹ̀;
Wundia ọmọbirin Sioni ti kẹgàn rẹ, o si ti
fi ọ rẹrin ẹlẹyà; ọmọbirin Jerusalemu ti
mì ori rẹ̀ si ọ.
22 Tani iwọ sọ̀rọ buburu si ti iwọ si kẹ-
gàn? ati tani iwọ gbé ohùn rẹ si òke si, ti
iwọ gbé oju rẹ ga si òke? ani si Ẹni-
Mimọ Israeli.
23 Nipa awọn onṣẹ rẹ, iwọ ti sọ̀rọ bu-
buru si Oluwa, ti nwọn si wipe, Ọpọlọpọ
kẹkẹ́ mi li emi fi de ori awọn òke-nla, si
ori Lebanoni, emi o si ké igi kedari giga rẹ̀
lulẹ, ati ãyò igi firi rẹ̀; emi o si lọ si ori
òke ibùwọ rẹ̀, sinu igbó Karmeli rẹ̀.
24 Emi ti wà kànga, emi si ti mu ajẹ̀ji
omi, atẹlẹsẹ̀ mi li emi si ti fi gbẹ gbogbo
odò Egipti.
25 Iwọ kò ti gbọ́, lailai ri emi ti ṣe e,
nigba atijọ emi si ti mura tẹlẹ nisisiyi emi
ti mu u ṣẹ, ki iwọ ki o le mã sọ ilu olodi
wọnni di ahoro, ani di òkiti àlapa.
26 Nitorina ni awọn olugbe wọn fi ṣe
alainipa, a daiyàfo wọn nwọn si dãmu;
nwọn dàbi koriko igbẹ́, ati bi ewebẹ̀ tutù,
bi koriko li ori ile, ati bi ọkà ti o rẹ̀ danù
ki o to dàgba soke.
27 Ṣugbọn emi mọ̀ ijoko rẹ, ati ijadelọ
rẹ, ati bibọ̀ rẹ, ati ikannu rẹ si mi.
28 Nitori ikánnu rẹ si mi ati irera rẹ de
eti mi, nitorina li emi o fi ìwọ̀ mi kọ́ ọ ni
imu, ati ijanu mi si ẹnu rẹ, emi o si yi ọ
pada si ọ̀na na ti iwọ ti ba wá.
29 Eyi ni yio si ṣe àmi fun ọ, Ẹ jẹ italẹ̀hu
ọdun ni, ati li ọdun keji eyiti o hù ninu
ọkanna; ati li ọdun kẹta ẹ fun irúgbìn, ki
ẹ si kore, ki ẹ si gbìn ọgba ajara, ki ẹ si jẹ
eso rẹ̀.
30 Iyokù ile Juda ti o salà yio si tún ta
gbòngbo si isàlẹ, yio si so eso li òke.
31 Nitori lati Jerusalemu li awọn iyokù
yio jade lọ, ati awọn ti o salà lati oke
Sioni jade: itara Oluwa awọn ọmọ-ogun ni
yio ṣe eyi.
32 Nitori bayi li Oluwa wi niti ọba
Assiria, On kì yio wá si ilu yi, bẹ̃ni kì yio
ta ọfà kan sibẹ, kì yio mu asà wá iwaju rẹ̀,
bẹ̃ni kì yio mọ odi tì i yika.
33 Ọna na ti o ba wá, ọkanna ni yio ba
pada lọ, kì yio si wá si ilu yi, li Oluwa wi.
34 Nitori emi o dá abò bò ilu yi, lati
gbà a, nitori ti emi tikara mi, ati nitori ti
Dafidi iranṣẹ mi.
35 O si ṣe li oru na ni angeli Oluwa jade
lọ, o si pa ọkẹ́ mẹsan le ẹgbẹ̃dọgbọn enia ni
ibùbo awọn ara Assiria: nigbati nwọn si
dide ni kutukutu owurọ, kiyesi i, okú ni
gbogbo wọn jasi.
36 Bẹ̃ni Sennakeribu ọba Assiria mu

Digitized by Google

a rẹ̀ pọ̀n, o si lọ, o si pada, o si joko ni
nefe.
37 O si ṣe, bi o ti mbọ̀riṣa ni ile Nisroku
ṣa rẹ̀, ni Adrammeleki ati Ṣareseri awọn
ọ rẹ̀ fi idà pa a: nwọn si sa lọ si ilẹ
menia. Esarhaddoni ọmọ rẹ̀ si jọba ni
rẹ̀.

## ORI 20.

I ọjọ wọnni ni Hesekiah ṣe aisàn de oju-
ikú. Isaiah woli ọmọ Amosi si tọ̀ ọ
, o si wi fun u pe, Bayi li Oluwa wi,
lẹ ile rẹ mọ́; nitoriti iwọ o kú, iwọ kì
si yè.
2 Nigbana ni o yi oju rẹ̀ pada si ogiri, o
gbadura si Oluwa, wipe,
3 Emi bẹ̀ ọ, Oluwa, ranti nisisiyi bi emi
rìn niwaju rẹ ninu otitọ ati ninu aiya
e, ti mo si ti ṣe eyiti o dara li oju rẹ.
sekiah si sọkún gidigidi.
4 O si ṣe, ki Isaiah ki o to jade si ãrin
alá-ãfin, li ọ̀rọ Oluwa tọ̀ ọ wá wipe,
5 Tun pada, ki o si wi fun Hesekiah
ri awọn enia mi pe, Bayi li Oluwa
run Dafidi baba rẹ wi pe, Emi ti gbọ́
ra rẹ, emi si ti ri omije rẹ: kiyesi i,
i o wò ọ sàn: ni ijọ kẹta iwọ o gòke lọ
le Oluwa.
6 Emi o si bù ọdun mẹ̃dogun kún ọjọ
emi o si gbà ọ ati ilu yi lọwọ ọba
iria, emi o si dãbò bò ilu yi, nitori ti emi
ara mi, ati nitori ti Dafidi iranṣẹ mi.
Isaiah si wipe, Mu odidi ọ̀pọtọ.
ọn si mu u, nwọn si fi le õwo na, ara
i da.
Hesekiah si wi fun Isaiah pe, Kini yio
mi pe Oluwa yio wò mi sàn, ati pe emi
òke lọ si ile Oluwa ni ijọ kẹta?
Isaiah si wipe, Àmi yi ni iwọ o ni lati
Olúwa wá, pe, Oluwa yio ṣe nkan yi ti
ti sọ: ki ojiji ki o lọ siwaju ni iṣisẹ̀
va ni, tabi ki o pada sẹhin ni iṣisẹ̀
va?
0 Hesekiah si dahùn wipe, Ohun ti o
n ni fun ojiji ki o lọ siwaju ni iṣisẹ̀
va: bẹ̀kọ, ṣugbọn jẹ ki ojiji ki o pada
n ni iṣisẹ̀ mẹwa.
1 Isaiah woli si kepè Oluwa; on si mu
pada sẹhin ni iṣisẹ̀ mẹwa, nipa eyiti o
kalẹ ninu agogo-õrùn Ahasi.
2 Li akokò na ni Berodaki-Baladani,
Baladani, ọba Babeli, rán iwe ati ọrẹ
esekiah: nitoriti o ti gbọ́ pe Hesekiah
aisàn.
3 Hesekiah si fi eti si ti wọn, o si fi
gbo ile iṣura ohun iyebiye rẹ̀ hàn wọn,
fadakà, ati wura, ati turari, ati ororo iye-
biye, ati gbogbo ile ohun ihamọra rẹ̀, ati
gbogbo eyiti a ri ninu iṣura rẹ̀: kò si nkan
ni ile rẹ̀, tabi ni gbogbo ijọba rẹ̀, ti Hese-
kiah kò fi hàn wọn.
14 Nigbana ni Isaiah woli wá si ọdọ
Hesekiah ọba, o si wi fun u pe, Kili awọn
ọkọnrin wọnyi wi? ati nibo ni nwọn ti wá
si ọdọ rẹ? Hesekiah si wipe, Ilu òkere ni
nwọn ti wá, ani lati Babeli:
15 On si wipe, Kini nwọn ri ni ile rẹ?
Hesekiah si dahùn wipe, Gbogbo nkan ti
mbẹ ni ile mi ni nwọn ti ri: kò si nkan
ninu iṣura mi ti emi kò fi hàn wọn.
16 Isaiah si wi fun Hesekiah pẹ, Gbọ́
ọ̀rọ Oluwa.
17 Kiyesi i, ọjọ mbọ̀, ti a o kó gbogbo
nkan ti mbẹ ninu ile rẹ, ati eyiti awọn
baba rẹ ti tò jọ titi di oni, lọ si Babeli:
ohun kan kì yio kù, li Oluwa wi.
18 Ati ninu awọn ọmọ rẹ ọkọnrin ti yio
ti inu rẹ jade wá, ti iwọ o bi, ni nwọn o
kó lọ; nwọn o si mã ṣe iwẹ̀fa li ãfin ọba
Babeli.
19 Nigbana ni Hesekiah wi fun Isaiah
pe, Rere li ọ̀rọ Oluwa ti iwọ sọ. On si
wipe, kò ha dara bi alafia ati otitọ ba wà
lọjọ mi?
20 Ati iyokù iṣe Hesekiah ati gbogbo
agbara rẹ̀, ati bi o ti ṣe adagun omi, ati
ọ̀na omi na, ti o si mu omi wá sinu ilu, a
kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba
Juda?
21 Hesekiah si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀:
Manasse ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 21.

ENI ọdun mejila ni Manasse nigbati o
bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba li ọdun marun-
dilọgọta ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ ni
Hefsiba.
2 O si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa, bi
iṣe-irira ti awọn keferi, ti Oluwa tì jade
niwaju awọn ọmọ Israeli.
3 Nitoriti o tun kọ́ ibi giga wọnni ti
Hesekiah baba rẹ̀ ti parun; o si tẹ́ pẹpẹ
fun Baali o si ṣe ere-oriṣa, bi Ahabu, ọba
Israeli ti ṣe, o si mbọ gbogbo ogun ọrun, o
si nsìn wọn.
4 O si tẹ́ pẹpẹ ni ile Oluwa, eyiti Oluwa
ti sọ pe, Ni Jerusalemu li emi o fi orukọ
mi si.
5 On si tẹ́ pẹpẹ fun gbogbo ogun ọrun li
agbalá mejeji ile Oluwa.
6 On si mu ki ọmọ rẹ̀ ki o kọja lãrin iná,

Digitized by Google

a si mã ṣe akiyesi afọṣẹ, a si mã ṣe alupà-
yida, a si mã bá awọn ọkú ati awọn oṣó lò:
o hùwa buburu pupọ̀ li oju Oluwa lati mu
u binu.
7 O si gbé ere oriṣa fifin kalẹ ti o ti ṣe
ni ile na ti Oluwa sọ fun Dafidi ati Solo-
moni ọmọ rẹ̀ pe, Ni ile yi, ati ni Jerusa-
lemu, ti mo ti yàn ninu gbogbo awọn ẹ̀ya
Israeli, li emi o fi orukọ mi si lailai:
8 Bẽni emi kì yio si jẹ ki ẹsẹ̀ Israeli ki
o yẹ̀ kuro mọ ni ilẹ ti mo fi fun awọn baba
wọn; kiki bi nwọn o ba ṣe akiyesi lati ṣe
gẹgẹ bi gbogbo eyiti mo pa li aṣẹ fun wọn,
ati gẹgẹ bi gbogbo ofin ti Mose iranṣẹ mi
pa li aṣẹ fun wọn.
9 Ṣugbọn nwọn kò feti silẹ: Manasse si
tàn wọn lati ṣe buburu jù eyiti awọn orilẹ̀-
ède ti Oluwa ti parun niwaju awọn ọmọ
Israeli ti ṣe.
10 Oluwa si wi nipa awọn woli iranṣẹ
rẹ̀ pe,
11 Nitoriti Manasse ọba Juda ti ṣe ohun-
irira wọnyi, ti o si ti ṣe buburu jù gbogbo
eyiti awọn ọmọ Amori ti ṣe, ti o ti wà ṣãju
rẹ̀, ti o si mu ki Juda pẹlu ki o fi awọn ere
rẹ̀ dẹṣẹ:
12 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli
wi, Kiyesi i, emi nmu iru ibi bayi wá sori
Jerusalemu ati Juda, ti ẹnikẹni ti o ba gbọ́
ọ, eti rẹ̀ mejeji yio ho.
13 Emi o si nà okùn Samaria lori Jeru-
salemu, ati òjé-idiwọ̀n ile Ahabu: emi o si
nù Jerusalemu bi enia ti nnù awokoto, o
nnù u, o si ndori rẹ̀ kodò.
14 Emi o si kọ̀ iyokù awọn ini mi silẹ,
emi o si fi wọn le awọn ọ̀ta wọn lọwọ;
nwọn o si di ikogun ati ijẹ fun gbogbo
awọn ọ̀ta wọn.
15 Nitori nwọn ti ṣe eyiti o buru li oju
mi, ti nwọn si ti mu mi binu, lati ọjọ ti
awọn baba wọn ti jade kuro ni Egipti, ani
titi di oni yi.
16 Pẹlupẹlu Manasse ta ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ silẹ
pupọjù, titi o fi kún Jerusalemu lati ikan-
gun ikini de ekeji; lẹhin ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o mu
Juda ṣẹ̀, ni ṣiṣe buburu li oju Oluwa.
17 Ati iyokù iṣe Manasse, ati gbogbo
eyiti o ṣe, ati ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ṣẹ̀, a kò ha kọ wọn
sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Juda?
18 Manasse si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a
si sin i ninu ọgba-ile rẹ̀, ninu ọgba Ussa:
Amoni ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
19 Ẹni ọdun mejilelogun ni Amoni ni-
gbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba li ọdun meji
ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ ni Mesulle-
meti, ọmọbirin Harusi ti Jotba.
20 On si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa, bi
baba rẹ̀ Manasse ti ṣe.
21 O si rìn li ọ̀na gbogbo ti baba rẹ̀ rìn,
o si sìn awọn ere ti baba rẹ̀ sìn, o si bọ
wọn:
22 On si kọ̀ Oluwa Ọlọrun awọn baba rẹ̀
silẹ, kò si rìn li ọ̀na Oluwa.
23 Awọn iranṣe Amoni si dìtẹ si i, nwọn
si pa ọba ni ile rẹ̀.
24 Awọn enia ilẹ na si pa gbogbo awọn
ti o dìtẹ si Amoni ọba: awọn enia ilẹ na si
fi Josiah ọmọ rẹ̀ jọba ni ipò rẹ̀.
25 Ati iyokù iṣe Amoni ti o ti ṣe, a kò
ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba
Juda?
26 A si sìn i ni isà okú rẹ̀ ninu ọgba
Ussa: Josiah ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 22.

ENI ọdun mẹjọ ni Josiah nigbati o bẹ̀rẹ
si ijọba; o si jọba li ọdun mọkanle-
lọgbọ̀n ni Jerusalemu, Orukọ iya rẹ̀ ni
Jedida, ọmọbirin Adaiah ti Boskati.
2 On si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa o si rìn
li ọ̀na Dafidi baba rẹ̀ gbogbo, kò si yipada
si apa ọ̀tún tabi si apa òsi.
3 O si ṣe li ọdun kejidilogun Josiah ọba
li ọba rán Ṣafani ọmọ Asaliah ọmọ Mesul-
lamu, akọwe, si ile Oluwa, wipe,
4 Gòke tọ̀ Hilkiah olori alufa lọ, ki o le
ṣirò iye fadakà ti a mu wá sinu ile Oluwa,
ti awọn olùtọju iloro ti kojọ lọwọ awọn
enia:
5 Ẹ si jẹ ki wọn ki o fi le awọn olùṣe iṣẹ
na lọwọ, ti nṣe alabojuto ile Oluwa: ki ẹ
si jẹ ki wọn ki o fi fun awọn olùṣe iṣẹ na
ti mbẹ ninu ile Oluwa, lati tun ibi ẹya ile
na ṣe.
6 Fun awọn gbẹnagbẹna, ati fun awọn
akọle, ati awọn ọ̀mọle, lati rà ìti-igi ati
okuta gbígbẹ lati tún ile na ṣe.
7 Ṣugbọn a kò ba wọn ṣe iṣirò owo ti a fi
le wọn lọwọ, nitoriti nwọn ṣe otitọ.
8 Hilkiah olori alufa si sọ fun Ṣafani
akọwe pe, Emi ri iwe ofin ni ile Oluwa.
Hilkiah si fi iwe na fun Ṣafani, on si
kà a.
9 Ṣafani akọwe si wá sọdọ ọba, o si tún
mu èsi pada fun ọba wá, o si wipe, Awọn
iranṣẹ rẹ ti kó owo na jọ ti a ri ni ile na,
nwọn si ti fi le ọwọ awọn ti o nṣiṣẹ na, ti
nṣe alabojuto ile Oluwa.
10 Ṣafani akọwe si fi hàn ọba, pe, Hil-
kiah alufa fi iwe kan le mi lọwọ. Ṣafani
si kà a niwaju ọba.

Digitized by Google

11 O si ṣe, nigbati ọba gbọ́ ọ̀rọ inu iwe
ofin na, o si fà aṣọ rẹ̀ ya.
12 Ọba si paṣẹ fun Hilkiah alufa, ati
Ahikamu ọmọ Ṣafani, ati Akbori ọmọ
Mikaiah, ati Ṣafani akọwe, ati Asahiah
iranṣẹ ọba wipe,
13 Ẹ lọ, ẹ bère lọwọ Oluwa fun mi, ati
fun awọn enia, ati fun gbogbo Juda, niti
ọ̀rọ iwe yi ti a ri: nitori titobi ni ibinu
Oluwa ti o rú si wa, nitori awọn baba wa
kò fi eti si ọ̀rọ iwe yi, lati ṣe gẹgẹ bi gbo-
gbo eyiti a kọwe silẹ fun wa.
14 Bẽni Hilkiah alufa, ati Ahikamu, ati
Akbori, ati Ṣafani, ati Asahiah tọ̀ Hulda
woli obirin lọ, aya Ṣallumu, ọmọ Tikfa,
ọmọ Harhasi, alabojuto aṣọ (nje on ngbe
Jerusalemu niha keji); nwọn si ba a sọ̀rọ.
15 On si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa
Ọlọrun Israeli wi, Sọ fun ọkọnrin ti o rán
nyin si mi pe,
16 Bayi li Oluwa wi, Kiyesi i, emi o mu
ibi bá ibiyi, ati bá awọn ara ilu na, ani
gbogbo ọ̀rọ iwe na ti ọba Juda ti kà.
17 Nitoriti nwọn ti kọ̀ mi silẹ, nwọn si
ti nsun turari fun awọn ọlọrun miran, ki
nwọn ki o le fi gbogbo iṣẹ ọwọ wọn mu
mi binu; nitorina ibinu mi yio rú si ibi yi,
ki yio si rọlẹ.
18 Ṣugbọn fun ọba Juda ti o rán nyin
wá ibère lọdọ Oluwa, bayi li ẹnyin o sọ
fun u, Bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi, niti
ọ̀rọ wọnni ti iwọ ti gbọ́:
19 Nitoriti ọkàn rẹ rọ̀, ti iwọ si ti rẹ̀ ara
rẹ silẹ niwaju Oluwa, nigbati iwọ gbọ́ eyiti
mo sọ si ibi yi, ati si awọn ara ilu na pe,
nwọn o di ahoro ati ẹni-ègun, ti iwọ si fà
aṣọ rẹ ya ti o si sọkun niwaju mi; emi pẹlu
ti gbọ́ tirẹ, li Oluwa wi.
20 Nitorina kiyesi i, emi o kó ọ jọ sọdọ
awọn baba rẹ, a o si kó ọ jọ sinu isà-okú
rẹ li alafia; oju rẹ ki o si ri gbogbo ibi
ti emi o mu wá bá ibi yi. Nwọn si tún
mu èsi fun ọba wá.

## ORI 23.

ỌBA si ranṣẹ, nwọn si pè gbogbo awọn
àgba Juda ati Jerusalemu jọ sọdọ rẹ̀.
2 Ọba si gòke lọ sinu ile Oluwa, ati
gbogbo awọn enia Juda ati gbogbo olugbe
Jerusalemu pẹlu rẹ̀, ati awọn alufa, ati
awọn woli ati gbogbo enia, ati ewe ati
àgba: o si kà gbogbo ọ̀rọ inu iwe majẹmu
na ti a ri ninu ile Oluwa li etí wọn.
3 Ọba si duro ni ibuduro na, o si dá
majẹmu niwaju Oluwa, lati mã fi gbogbo
aiya ati gbogbo ọkàn rìn tọ̀ Oluwa lẹhin,
ati lati pa ofin rẹ̀ mọ́, ati ẹri rẹ̀, ati aṣẹ rẹ̀,
lati mu ọ̀rọ majẹmu yi ṣẹ, ti a ti kọ ninu
iwe yi. Gbogbo awọn enia si duro si majẹ-
mu na.
4 Ọba si paṣẹ fun Hilkiah olori alufa,
ati awọn alufa ẹgbẹ keji, ati awọn alabojuto
iloro, lati kó gbogbo ohun-èlo ti a ṣe fun
Baali, ati fun ere òriṣa, ati fun gbogbo
ogun ọrun jade kuro ni tempili Oluwa: o
si sun wọn lẹhin ode Jerusalemu ninu pápa
Kidroni, o si kó ẽru wọn lọ si Beteli.
5 O si dá awọn baba-loriṣa lẹkun, ti
awọn ọba Juda ti yàn lati ma sun turari ni
ibi giga ni ilu Juda wọnni, ati ni ibi ti o yi
Jerusalemu ka; awọn pẹlu ti nsun turari
fun Baali, fun õrùn, ati fun òṣupa, ati fun
awọn àmi mejila irawọ, ati fun gbogbo
ogun ọrun.
6 O si gbé ere-oriṣa jade kuro ni ile
Oluwa, sẹhin ode Jerusalemu lọ si odò
Kidroni, o si sun u nibi odò Kidroni, o si
lọ̀ ọ lũlu, o si dà ẹ̀tu rẹ̀ sori isà-okú awọn
ọmọ enia na.
7 O si wó ile awọn ti nhù iwa panṣaga,
ti mbẹ leti ile Oluwa, nibiti awọn obirin
wun aṣọ-agọ fun ere-oriṣa.
8 O si kó gbogbo awọn alufa jade kuro
ni ilu Juda wọnni, o si sọ ibi giga wọnni di
ẽri nibiti awọn alufa ti sun turari, lati
Geba titi de Beer-ṣeba, o si wó ibi giga
ẹnu-ibodè wọnni ti mbẹ ni atiwọ̀ ẹnu-ibodè
Joṣua bãlẹ ilu, ti mbẹ lapa osi ẹni, ni atiwọ̀
ẹnu-ibode ilu.
9 Ṣugbọn awọn alufa ibi giga wọnni kò
gòke wá si ibi pẹpẹ Oluwa ni Jerusalemu,
ṣugbọn nwọn jẹ ninu àkara alaiwu lãrin
awọn arakọnrin wọn.
10 On si sọ Tofeti di ẽri, ti mbẹ ni
afonifojì awọn ọmọ Hinnomu, ki ẹnikan ki
o máṣe mu ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, tabi ọmọ rẹ̀
obirin là ãrin iná kọja fun Moleki.
11 O si mu ẹṣin wọnni kuro ti awọn ọba
Juda ti fi fun õrun, ni atiwọ̀ inu ile Oluwa
lẹba iyẹ̀wu Natan-meleki iwẹ̀fa, ti o ti wà
ni agbegbe tempili, o si fi iná sun kẹkẹ́
õrun wọnni.
12 Ati pẹpẹ wọnni ti mbẹ lori iyara òke
Ahasi, ti awọn ọba Juda ti tẹ́, ati pẹpẹ
wọnni ti Manasse ti tẹ́ li ãfin mejeji ile
Oluwa ni ọba wó lulẹ, o si yara lati ibẹ, o
si da ekuru wọn sinu odò Kidroni.
13 Ati ibi giga wọnni ti o wà niwaju
Jerusalemu, ti o wà li ọwọ ọtún òke idibà-
jẹ, ti Solomoni ọba Israeli ti kọ́ fun Aṣto-
reti ohun irira awọn ara Sidoni, ati fun
Kemoṣi ohun irira awọn ara Moabu, ati fun

Digitized by Google

Milkomu ohun-irira awọn ọmọ Ammoni li ọba sọ di ẽri.

14 O si fọ́ awọn ere na tũtu, o si wó awọn ere-oriṣa lulẹ, o si fi egungun enia kún ipò wọn.

15 Ati pẹlu, pẹpẹ ti o ti wà ni Beteli, ati ibi giga ti Jeroboamu ọmọ Nebati, ẹniti o mu Israeli ṣẹ̀, ti tẹ́, ati pẹpẹ na, ati ibi giga na ni o wó lulẹ, o si sun ibi giga na, o si lọ̀ ọ lũlu, o si sun ere-oriṣa na.

16 Bi Josiah si ti yira pada, o ri awọn isà-okú ti o wà lori òke, o si ranṣẹ, o si kó awọn egungun lati inu isà wọnni kuro, o si sun wọn lori pẹpẹ na, o si sọ ọ di ẽri, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, ti enia Ọlọrun nì ti kede, ẹniti o kede ọ̀rọ wọnyi.

17 Nigbana li o wipe, Ọwọ̀n isa-okú wo li eyi ti mo ri nì? Awọn enia ilu na si sọ fun u pe, Isà-okú enia Ọlọrun nì ni, ti o ti Juda wá, ti o si kede nkan wọnyi ti iwọ ti ṣe si pẹpẹ Beteli.

18 On si wipe, Jọwọ rẹ̀; máṣe jẹ ki ẹnikan ki o mu egungun rẹ̀ kuro. Bẹ̃ni nwọn jọwọ egungun rẹ̀ lọwọ, pẹlu egungun woli ti o ti Samaria wá.

19 Ati pẹlu gbogbo ile ibi-giga wọnni ti o wà ni ilu Samaria wọnni, ti awọn ọba Israeli ti kọ́ lati rú ibinu Oluwa soke ni Josiah mu kuro, o si ṣe si wọn gẹgẹ bi gbogbo iṣe ti o ṣe ni Beteli.

20 O si pa gbogbo awọn alufa ibi giga wọnni ti o wà nibẹ lori awọn pẹpẹ na, o si sun egungun enia lori wọn, o si pada si Jerusalemu.

21 Ọba si paṣẹ fun gbogbo enia, wipe, Pa irekọja mọ́ fun Oluwa Ọlọrun nyin, bi a ti kọ ọ ninu iwe majẹmu yi.

22 Nitõtọ a kò ṣe iru irekọja bẹ̃ lati ọjọ awọn onidajọ ti ndajọ ni Israeli, tabi ni gbogbo ọjọ awọn ọba Israeli tabi awọn ọba Juda;

23 Ṣugbọn li ọdun kejidilogun Josiah ọba, ni a pa irekọja yi mọ́ fun Oluwa ni Jerusalemu.

24 Ati pẹlu awọn ti mba awọn okú lò, ati awọn oṣo, ati awọn ere, ati awọn oriṣa, ati gbogbo irira ti a ri ni ilẹ Juda ati ni Jerusalemu ni Josiah kó kuro, ki o le mu ọ̀rọ ofin na ṣẹ ti a ti kọ sinu iwe ti Hilkiah alufa ri ni ile Oluwa.

25 Kò si si ọba kan ṣãju rẹ̀, ti o dabi rẹ̀, ti o yipada si Oluwa tinutinu ati tọkàntọkàn ati pẹlu gbogbo agbara rẹ̀, gẹgẹ bi gbogbo ofin Mose; bẹ̃ni lẹhin rẹ̀, kò si ẹnikan ti o dide ti o dàbi rẹ̀.

26 Ṣugbọn Oluwa kò yipada kuro ninu mimuná ibinu nla rẹ̀, eyiti ibinu rẹ̀ fi ràn si Juda, nitori gbogbo imunibinu ti Manasse ti fi mu u binu.

27 Oluwa si wipe, Emi o si mu Juda kuro loju mi pẹlu, bi mo ti mu Israeli kuro, emi o si ta ilu Jerusalemu yi nù, ti mo ti yàn, ati ile eyiti mo wipe, Orukọ mi yio wà nibẹ.

28 Ati iyokù iṣe Josiah ati gbogbo eyiti o ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn ọba Juda?

29 Li ọjọ rẹ̀ ni Farao-Neko ọba Egipti dide ogun si ọba Assiria li odò Euferate: Josiah ọba si dide si i; on si pa a ni Megiddo, nigbati o ri i.

30 Awọn iranṣẹ rẹ̀ si gbé e li okú ninu kẹkẹ́ lati Megiddo lọ, nwọn si mu u wá si Jerusalemu, nwọn si sìn i ni isà-okú ontikalarẹ̀. Awọn enia ilẹ na si mu Jehoahasi ọmọ Josiah, nwọn si fi ororo yàn a, nwọn si fi i jọba ni ipò baba rẹ̀.

31 Ẹni ọdun mẹtalelogun ni Jehoahasi nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba; o si jọba li oṣù mẹta ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ ni Hamutali, ọmọbirin Jeremiah ti Libna,

32 On si ṣe eyiti o buru li loju Oluwa, gẹgẹ bi gbogbo eyiti awọn baba rẹ̀ ti ṣe.

33 Farao-Neko si fi i sinu idè ni Ribla, ni ilẹ Hamati, ki o má ba jọba ni Jerusalemu; o si fi ilẹ na si abẹ isìn li ọgọrun talenti fadakà, ati talenti wura.

34 Farao-Neko si fi Eliakimu ọmọ Josiah jẹ ọba ni ipò Josiah baba rẹ̀, o si pa orukọ rẹ̀ dà si Jehoiakimu, o si mu Jehoahasi kuro; on si wá si Egipti, o si kú nibẹ.

35 Jehoiakimu si fi fadakà ati wura na fun Farao; ṣugbọn o bu owo-odè fun ilẹ na lati san owo na gẹgẹ bi ofin Farao: o fi agbara gbà fadakà ati wurà na lọwọ awọn enia ilẹ na, lọwọ olukuluku gẹgẹ bi owo ti a bù fun u, lati fi fun Farao-Neko.

36 Ẹni ọdun mẹ̃dọgbọ̀n ni Jehoiakimu nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba; o si jọba ọdun mọkanla ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ ni Sebuda, ọmọbirin Bedaiah ti Ruma.

37 On si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa, gẹgẹ bi gbogbo eyiti awọn baba rẹ̀ ti ṣe.

## ORI 24.

LI ọjọ rẹ̀ ni Nebukadnessari ọba Babeli gòke wá, Jehoiakimu si di iranṣẹ rẹ̀ li ọdun mẹta: nigbana li o pada o si ṣọ̀tẹ si i.

2 Oluwa si rán ẹgbẹ́ ogun awọn ara Kaldea si i, ati ẹgbẹ́ ogun awọn ara Siria, ati ẹgbẹ́ ogun awọn ara Moabu, ati ẹgbẹ́ ogun awọn ọmọ Ammoni, o si rán wọn si

Digitized by Google

da lati pa a run, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, ti o
sọ nipa awọn iranṣẹ rẹ̀ awọn woli.
3 Nitõtọ lati ẹnu Oluwa li eyi ti wá sori
da, lati mu wọn kuro niwaju rẹ̀, nitori
Manasse, gẹgẹ bi gbogbo eyiti o ṣe;
4 Ati nitori ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ ti o ta silẹ pẹlu:
oriti o fi ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ kún Jerusalemu; ti
uwa kò fẹ dariji.
5 Ati iyokù iṣe Jehoiakimu, ati gbogbo
iti o ṣe, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ
ọn ọba Juda?
6 Bẹ̃ni Jehoiakimu sùn pẹlu awọn baba
: Jehoiakini ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.
7 Ọba Egipti kò si tun jade kuro ni ilẹ
mọ; nitori ọba Babeli ti gbà gbogbo
iti iṣe ti ọba Egipti lati odò Egipti wá
i de odò Ferate.
8 Ẹni ọdun mejidilogun ni Jehoiakini
gbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba li oṣù mẹta
Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ ni Nehuṣta,
ọbirin Elnatani ti Jerusalemu.
9 On si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa,
gẹ bi gbogbo eyiti baba rẹ̀ ti ṣe.
10 Li akokò na, awọn iranṣẹ Nebukad-
ssari ọba Babeli gbé ogun wá si Jerusa-
nu, a si dotì ilu na.
11 Nebukadnessari ọba Babeli si de si
na, nigbati awọn iranṣẹ rẹ̀ si dotì i.
12 Jehoiakini ọba Juda si jade tọ̀ ọba
beli lọ, on, ati iya rẹ̀, ati awọn iranṣẹ
ati awọn ijoye rẹ̀, ati awọn iwẹfa rẹ̀:
a Babeli si mu u li ọdun kẹjọ ijọba rẹ̀.
13 O si kó gbogbo iṣura ile Oluwa lọ
ro nibẹ, ati iṣura ile ọba, o si ké gbogbo
un-èlo wura wẹwẹ ti Solomoni ọba Isra-
ti ṣe ni tempili Oluwa, bi Oluwa ti sọ.
14 O si kó gbogbo Jerusalemu lọ, ati
ogbo awọn ijoye, ati gbogbo awọn ala-
ara akọni enia, ani ẹgbãrun igbèkun, ati
ogbo awọn oniṣọnà ati awọn alagbẹ̀dẹ:
kù ẹnikan, bikòṣe iru awọn ti o jẹ tala-
ninu awọn enia ilẹ na.
15 O si mu Jehoiakini lọ si Babeli, ati
ọba, ati awọn obirin ọba, ati awọn
ẹ̀fa rẹ̀, ati awọn alagbara ilẹ na, awọn
nyi li o kó ni igbèkun lati Jerusalemu
si Babeli.
16 Ati gbogbo awọn ọkọnrin ọlọla, ọdẹ-
ãrin, ati awọn oniṣọnà ati awọn alagbẹdẹ
bẹrun, gbogbo awọn ti o li agbara ti o si
fun ogun, ani awọn li ọba Babeli kó ni
bèkun lọ si Babeli.
17 Ọba Babeli si fi Mattaniah arakọnrin
ba rẹ̀ jọba ni ipò rẹ̀, o si pa orukọ rẹ̀ dà
Sedekiah.
18 Ẹni ọdun mọkanlelogun ni Sedekiah
nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba li ọdun
mọkanla ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ ni
Hamutali, ọmọbirin Jeremiah ti Libna.
19 O si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa,
gẹgẹ bi gbogbo eyiti Jehoiakimu ti ṣe.
20 Nitori nipa ibinu Oluwa li o ṣẹ si
Jerusalemu ati Juda, titi o fi ta wọn nù
kuro niwaju rẹ̀; Sedekiah si ṣọ̀tẹ si ọba
Babeli.

## ORI 25.

OSI ṣe li ọdun kẹsan ijọba rẹ̀, li oṣù kẹwa,
li ọjọ kẹwa oṣù, ni Nebukadnessari
ọba Babeli de, on, ati gbogbo ogun rẹ̀, si
Jerusalemu, o si dotì i; nwọn si mọdi tì i
yika kiri.
2 A si dotì ilu na titi di ọdun ikọkanla
Sedekiah.
3 Ati li ọjọ kẹsan oṣù kẹrin, iyàn mu
gidigidi ni ilu, kò si si onjẹ fun awọn enia
ilẹ na.
4 Ilu na si fọ́, gbogbo awọn ọkọnrin
ologun si gbà ọ̀na bodè lãrin odi meji, ti o
wà leti ọ̀gba ọba, salọ li oru; (awọn ara
Kaldea si yi ilu na kakiri;) ọba si ba ọ̀na
pẹ̀tẹlẹ lọ.
5 Ogun awọn ara Kaldea si lepa ọba,
nwọn si ba a ni pẹ̀tẹlẹ Jeriko: gbogbo
ogun rẹ̀ si tuka kuro lọdọ rẹ̀.
6 Bẹ̃ni nwọn mu ọba, nwọn si mu u gòke
lọ si ọdọ ọba Babeli ni Ribla; nwọn si sọ
ọ̀rọ idajọ lori rẹ̀.
7 Nwọn si pa awọn ọmọ Sedekiah li oju
rẹ̀, nwọn si fọ Sedekiah li oju, nwọn si fi
ẹwọn idẹ dè e, nwọn si mu u lọ si Babeli.
8 Ati li oṣù karun, li ọjọ keje oṣù, ti iṣe
ọdun ikọkandilogun Nebukadnessari ọba,
ọba Babeli, ni Nebusaradani olori ẹ̀ṣọ,
iranṣẹ ọba Babeli, wá si Jerusalemu:
9 O si fi ile Oluwa joná, ati ile ọba, ati
gbogbo ile Jerusalemu, ati gbogbo ile enia
nla li o fi iná sun.
10 Gbogbo ogun awọn ara Kaldea ti o
wà lọdọ olori ẹ̀ṣọ, si wó odi Jerusalemu
palẹ yika kiri.
11 Ati iyokù awọn enia ti o kù ni ilu
ati awọn isansa ti o ya tọ̀ ọba Babeli lọ,
pẹlu ọ̀pọlọpọ enia ti o kù, ni Nebusaradani
olori ẹ̀ṣọ kó lọ.
12 Ṣugbọn olori ẹ̀ṣọ fi awọn talakà ilẹ na
silẹ, lati mã ṣe alabojuto àjara ati lati mã
ṣe alaroko.
13 Ati ọwọ̀n idẹ wọnni ti mbẹ ni ile
Oluwa, ati ijoko wọnni, ati agbada-nla idẹ
ti o wà ni ile Oluwa, li awọn ara Kaldea fọ
tũtu, nwọn si kó idẹ wọn lọ si Babeli.

Digitized by Google

14 Ati ikòko wọnni, ati ọkọ wọnni, ati alumagàji fitila wọnni, ati ṣibi wọnni, ati gbogbo ohun-èlo wọnni ti nwọn fi nṣiṣẹ, ni nwọn kó lọ.

15 Ati ohun ifọnná wọnni, ati ọpọ́n wọnni, eyi ti iṣe ti wura, ni wura, ati eyi ti iṣe ti fadakà ni fadakà, ni olori ẹ̀ṣọ kó lọ.

16 Awọn ọ̀wọn meji, agbada-nla kan, ati ijoko wọnni ti Solomoni ti ṣe fun ile Oluwa; idẹ gbogbo ohun-èlo wọnyi, alaini ìwọn ni.

17 Giga ọwọ̀n kan ni igbọ̀nwo, mejidilogun, ati ọnà-ori rẹ̀ idẹ ni: ati giga ọnà-ori na ni igbọ̀nwọ mẹta; ati iṣẹ wiwun na, ati awọn pomegranate ti o wà lori ọnà-ori na yika kiri, gbogbo rẹ̀ ti idẹ ni: gẹgẹ bi awọn wọnyi si ni ọwọ̀n keji pẹlu iṣẹ wiwun.

18 Olori ẹ̀ṣọ si mu Seraiah olori ninu awọn alufa, ati Sefaniah alufa keji, ati awọn olùṣọ iloro mẹta.

19 Ati lati inu ilu, o mu iwẹ̀fa kan ti a fi ṣe olori awọn ologun, ati ọkọnrin marun ninu awọn ti o wà niwaju ọba, ti a ri ni ilu, ati akọwe olori ogun, ti ntò awọn enia ilẹ na, ati ọgọta ọkọnrin ninu awọn enia ilẹ na ti a ri ni ilu.

20 Nebusaradani olori ẹ̀ṣọ si kó awọn wọnyi, o si mu wọn tọ̀ ọba Babeli wá si Ribla.

21 Ọba Babeli si kọlù wọn, o si pa wọn ni Ribla ni ilẹ Hamati. Bẽli a mu Juda kuro ni ilẹ rẹ̀.

22 Ati awọn enia ti o kù ni ilẹ Juda, ti Nebukadnessari ọba Babeli fi silẹ, ani, o fi Gedaliah ọmọ Ahikamu, omọ Ṣafani, jẹ bãlẹ wọn.

23 Nigbati gbogbo awọn olori ogun, awọn ati awọn ọkọnrin wọn, si gbọ́ pe ọba Babeli ti fi Gedaliah jẹ bãlẹ, nwọn tọ̀ Gedaliah wá ni Mispa, ani Iṣmaeli ọmọ Netaniah, ati Johanani ọmọ Karea, ati Seraiah ọmọ Tanhumeti ara Netofati, ati Jaasaniah ọmọ ara Maaka, awọn ati awọn ọkọnrin wọn.

24 Gedaliah si bura fun wọn, ati fun awọn ọkọnrin wọn, o si wi fun wọn pe, Ẹ má bẹ̀ru lati sìn awọn ara Kaldea: ẹ mã gbe ilẹ na, ki ẹ si mã sìn ọba Babeli; yio si dara fun nyin.

25 O si ṣe li oṣù keje, ni Iṣmaeli ọmọ Netaniah, ọmọ Eliṣama ninu iru ọmọ ọba, wá, ati ọkọnrin mẹwa pẹlu rẹ̀, o si kọlù Gedaliah, o si kú, ati awọn ara Juda ati awọn ara Kaldea ti o wà pẹlu rẹ̀ ni Mispa.

26 Ati gbogbo enia, ti ewe ti àgba, ati awọn olori ogun, si dide, nwọn si wá si Egipti: nitoriti nwọn bẹ̀ru ara Kaldea.

27 O si ṣe li ọdun kẹtadilogoji igbèkun Jehoiakini ọba Juda, li oṣù kejila, li ọjọ kẹtadilọgbọn oṣù, Efil-merodaki ọba Babeli, li ọdun ti o bẹ̀re si ijọba, o gbé ori Jehoiakini ọba Juda soke kuro ninu tubu;

28 O si sọ̀rọ rere fun u, o si gbé ìtẹ rẹ̀ ga jù ìtẹ awọn ọba ti o wà pẹlu rẹ̀ ni Babeli

29 O si pàrọ awọn aṣọ tubu rẹ̀: o si njẹun nigbagbogbo niwaju rẹ̀ ni gbogbo ọjọ aiye rẹ̀.

30 Ati ipin onjẹ tirẹ̀, jẹ ipin onjẹ ti ọba nfi fun u nigbagbogbo, iye kan li ojojumọ, ni gbogbo ọjọ aiye rẹ̀.

---

IWE EKINI TI

# KRONIKA.

## ORI 1.

ADAMU, Seti, Enoṣi,

2 Kenani, Mahalaleeli, Jeredi,

3 Henoki, Metusela, Lameki,

4 Noa, Ṣemu, Hamu, ati Jafeti.

5 Awọn ọmọ Jafeti; Gomeri, ati Magogu, ati Madai, ati Jafani, ati Tubali, ati Meṣeki, ati Tirasi,

6 Ati awọn ọmọ Gomeri; Aṣkenasi, ati Rifati, ati Togarma.

7 Ati awọn ọmọ Jafani; Eliṣa, ati Tarṣiṣi, Kittimu, ati Dodanimu.

Digitized by Google

8 Awọn ọmọ Hamu; Kuṣi, ati Misraimu, Puti, ati Kenaani.

9 Ati awọn ọmọ Kuṣi; Ṣeba, ati Hafila, ati Sabta, ati Raama, ati Sabteka. Ati awọn ọmọ Raama; Ṣeba ati Dedani.

10 Kuṣi si bi Nimrodu: on bẹ̀rẹ si di alagbara li aiye.

11 Misraimu si bi Ludimu, ati Anamimu, ati Lehabimu, ati Naftuhimu,

12 Ati Patrusimu, ati Kasluhimu, (lọdọ ẹniti awọn ara Filistia ti wá,) ati Kaftorimu.

13 Kenaani si bi Sidoni akọbi rẹ̀, ati Heti,

14 Ati awọn ara Jebusi, ati awọn ara Amori, ati awọn ara Girgaṣi,

15 Ati awọn ara Hifi, ati awọn ara Arki, ati awọn ara Sini,

16 Ati awọn ara Arfadi, ati awọn ara Semari, ati awọn ara Hamati.

17 Awọn ọmọ Ṣemu; Elamu, ati Assuri, ati Arfaksadi, ati Ludi, ati Aramu, ati Usi, ati Huli, ati Geteri, ati Meṣeki.

18 Arfaksadi si bi Ṣela; Ṣela si bi Eberi.

19 Ati fun Eberi li a bi ọmọkọnrin meji: orukọ ọkan ni Pelegi: nitori li ọjọ rẹ̀ li a pin aiye niya: orukọ arakọnrin rẹ̀ si ni Joktani.

20 Joktani si bi Almodadi, ati Ṣelefi, ati Hasarmafeti, ati Jera,

21 Ati Hadoramu, ati Usali, ati Dikla,

22 Ati Ebali, ati Abimaeli, ati Ṣeba,

23 Ati Ofiri, ati Hafila, ati Jobabu. Gbogbo wọnyi li awọn ọmọ Joktani.

24 Ṣemu, Arfaksadi, Ṣela,

25 Eberi, Pelegi, Reu,

26 Serugu, Nahori, Tera,

27 Abramu; on na ni Abrahamu,

28 Awọn ọmọ Abrahamu; Isaaki, ati Iṣmaeli.

29 Wọnyi ni iran wọn: akọbi Iṣmaeli, Nebaioti; ati Kedari, ati Adbeeli, ati Mibsamu,

30 Miṣma, ati Duma, Massa, Hadadi, ati Tema,

31 Jeturi, Nafiṣi, ati Kedema. Wọnyi li awọn ọmọ Iṣmaeli.

32 Ati awọn ọmọ Ketura, obirin Abrahamu: on bi Simrani, ati Jokṣani, ati Medani, ati Midiani, ati Iṣbaki, ati Ṣua. Ati awọn ọmọ Jokṣani: Ṣeba, ati Dedani.

33 Ati awọn ọmọ Midiani: Efa, ati Eferi, ati Henoki, ati Abida, ani Eldaa. Gbogbo wọnyi li awọn ọmọ Ketura.

34 Abrahamu si bi Isaaki. Awọn ọmọ Isaaki; Esau ati Israeli.

35 Awọn ọmọ Esau; Elifasi, Reueli, ati Jeuṣi, ati Jaalamu, ati Kora.

36 Awọn ọmọ Elifasi; Temani, ati Omari, Sefi, ati Gatamu, Kenasi, ati Timna, ati Amaleki.

37 Awọn ọmọ Reueli: Nahati, Sera, Ṣamma, ati Missa.

38 Ati awọn ọmọ Seiri; Lotani, ati Ṣobali, ati Sibeoni, ati Ana, ati Diṣoni, ati Esari, ati Diṣani.

39 Ati awọn ọmọ Lotani; Hori, ati Homanu: Timna si ni arabirin Lotani.

40 Awọn ọmọ Ṣobali; Aliani, ati Manahati, ati Ebali, Ṣefi, ati Onamu. Ati awọn ọmọ Sibeoni; Aiah, ati Ana.

41 Awọn ọmọ Ana; Diṣoni. Ati awọn ọmọ Diṣoni; Amrani, ati Eṣbani, ati Itrani, ati Kerani.

42 Awọn ọmọ Eseri; Bilhani, ati Safani, ati Jakani. Awọn ọmọ Diṣani; Usi, ati Arani.

43 Wọnyi si ni awọn ọba ti o jẹ ni ilẹ Edomu, ki ọba kan to jẹ lori awọn ọmọ Israeli: Bela ọmọ Beori: orukọ ilu rẹ̀ si ni Dinhaba.

44 Nigbati Bela si kú, Jobabu ọmọ Sera ti Bosra si joba ni ipò rẹ̀.

45 Nigbati Jobabu kú, Huṣamu ti ilẹ awọn ara Temani si jọba ni ipò rẹ̀.

46 Nigbati Huṣamu kú, Hadadi ọmọ Bedadi, ti o kọlu Midiani ni ìgbẹ Moabu, jọba ni ipò rẹ̀: orukọ ilu rẹ̀ ni Afiti.

47 Nigbati Hadadi kú, Samla ti Masreka jọba ni ipò rẹ̀.

48 Nigbati Samla kú, Ṣaulu ti Rehoboti leti odò jọba ni ipò rẹ̀.

49 Nigbati Ṣaulu kú, Baal-hanani, ọmọ Akbori, jọba ni ipò rẹ̀.

50 Nigbati Baal-hanani kú, Hadadi si jọba ni ipò rẹ̀: orukọ ilu rẹ̀ ni Pai; orukọ aya rẹ̀ si ni Mehetabeeli, ọmọbirin Matredi, ọmọbirin Mesahabu.

51 Hadadi si kú. Awọn bãlẹ Edomu ni; Timna bãlẹ, Aliah bãlẹ, Jeteti bãlẹ.

52 Aholibama bãlẹ, Ela bãlẹ, Pinoni bãlẹ,

53 Kenasi bãlẹ, Temani bãlẹ, Mibsari bãlẹ,

54 Magdieli bãlẹ, Iramu bãlẹ. Wọnyi ni awọn bãlẹ Edomu.

## ORI 2.

WỌNYI ni awọn ọmọ Israeli; Rubeni, Simeoni, Lefi, ati Júda Issakari, ati Sebuluni,

Digitized by Google

2 Dani, Josefu, ati Benjamini, Naftali, Gadi, ati Aṣeri.
3 Awọn ọmọ Juda; Eri, ati Onani, ati Ṣela; awọn mẹta yi ni Batṣua, ara Kenaani, bi fun u. Eri, akobi Juda, si buru loju Oluwa; on si pa a.
4 Tamari aya-ọmọ rẹ̀ si bi Faresi ati Sera fun u. Gbogbo awọn ọmọ Juda jẹ marun.
5 Awọn ọmọ Faresi; Hesroni; ati Hamuli.
6 Ati awọn ọmọ Sera; Simri, ati Etani, ati Hemani, ati Kalkoli, ati Dara: gbogbo wọn jẹ marun.
7 Ati awọn ọmọ Karmi; Akari, oniyọnu Israeli, ẹniti o dẹṣẹ niti ohun iyasọtọ̀.
8 Awọn ọmọ Etani; Asariah.
9 Awọn ọmọ Hesroni pẹlu ti a bi fun u; Jerahmeeli, ati Ramu, ati Kelubai.
10 Ramu si bi Amminadabu; Amminadabu si bi Naṣoni, ijoye awọn ọmọ Juda;
11 Naṣoni si bi Salma, Salma si bi Boasi.
12 Boasi si bi Obedi, Obedi si bi Jesse,
13 Jesse si bi Eliabu akọbi rẹ̀, ati Abinadabu àtẹle, ati Ṣimma ẹkẹta.
14 Netanneeli ẹkẹrin, Raddai ẹkarun,
15 Osemu ẹkẹfa, Dafidi ekeje:
16 Awọn arabirin wọn ni Seruiah ati Abigaili. Ati awọn ọmọ Seruiah; Abiṣai, ati Joabu, ati Asaeli, mẹta.
17 Abigaili si bi Amasa: baba Amasa si ni Jeteri ara Iṣmeeli.
18 Kalebu ọmọ Hesroni si bi ọmọ lati ọdọ Asuba aya rẹ̀, ati lati ọdọ Jeriotu: awọn ọmọ rẹ̀ ni wọnyi; Jeṣeri ati Ṣobabu, ati Ardoni.
19 Nigbati Asuba kú, Kalebu mu Efrati, ẹniti o bi Huri fun u.
20 Huri si bi Uru, Uri si bi Besaleeli.
21 Lẹhin na Hesroni si wọle tọ̀ ọmọ Makiri obirin baba Gileadi, on gbe e ni iyawo nigbati o di ẹni ọgọta ọdun, on si bi Segubu fun u.
22 Segubu si bi Jairi, ti o ni ilu mẹtalelogun ni ilẹ Gileadi.
23 Ṣugbọn Geṣuri, ati Aramu, gbà ilu Jairi lọwọ wọn, pẹlu Kenati, ati ilu rẹ̀: ani ọgọta ilu. Gbogbo wọnyi ni awọn ọmọ Makiri baba Gileadi.
24 Ati lẹhin igbati Hesroni kú ni ilu Kaleb-Efrata, ni Abiah aya Hesroni bi Aṣuri baba Tekoa fun u.
25 Ati awọn ọmọ Jerahmeeli, akọbi Hesroni, ni Rama akọbi, ati Buna, ati Oreni, ati Osemu, ati Ahijah.
26 Jerahmeeli si ni obirin miran pẹlu, orukọ ẹniti ijẹ Atara; on ni iṣe iya Onamu.
27 Awọn ọmọ Ramu akọbi Jerahmeeli ni, Maasi, ati Jamini, ati Ekeri.
28 Awọn ọmọ Onamu si ni, Ṣammai, ati Jada. Awọn ọmọ Ṣammai ni; Nadabu ati Abiṣuri.
29 Orukọ aya Abiṣuri si njẹ Abihaili, on si bi Abani, ati Molidi fun u.
30 Ati awọn ọmọ Nadabu; Seledi, ati Appaimu: ṣugbọn Seledi kú laini ọmọ.
31 Ati awọn ọmọ Appaimu; Iṣi. Ati awọn ọmọ Iṣi; Ṣeṣani. Ati awọn ọmọ Ṣeṣani. Ahlai.
32 Ati awọn ọmọ Jaka arakọnrin Ṣammai; Jeteri, ati Jonatani; Jeteri si kú laini ọmọ.
33 Awọn ọmọ Jonatani; Peleti, ati Sasa. Wọnyi ni awọn ọmọ Jerahmeeli.
34 Ṣeṣani kò si ni ọmọkọnrin, bikoṣe ọmọbirin. Ṣeṣani si ni iranṣẹ kan, ara Egipti, orukọ ẹniti ijẹ Jarha.
35 Ṣeṣani si fi ọmọbirin rẹ̀ fun Jarha iranṣẹ rẹ̀ li aya; on si bi Attai fun u.
36 Attai si bi Natani, Natani si bi Sabadi,
37 Sabadi si ba Eflali, Eflali si bi Obedi,
38 Obedi si bi Jehu, Jehu si bi Asariah,
39 Asariah si bi Helesi, Helesi si bi Elasa,
40 Elasa si bi Sisamai, Sisamai si bi Ṣallumu,
41 Ṣallumu si bi Jekamiah, Jekamiah si bi Eliṣama.
42 Awọn ọmọ Kalebu arakọnrin Jerahmeeli si ni Mẹsa akọbi rẹ̀, ti iṣe baba Sifi; ati awọn ọmọ Mareṣa baba Hebroni.
43 Awọn ọmọ Hebroni; Kora, ati Tappua, ati Rekemu, ati Ṣema.
44 Ṣema si bi Rahamu, baba Jorkeamu: Rekemu si bi Ṣammai.
45 Ati ọmọ Ṣammai ni Maoni: Maoni si ni baba Bet-suri.
46 Efa obirin Kalebu si bi Harani, ati Mosa, ati Gasesi: Harani si bi Gasesi.
47 Ati awọn ọmọ Jahdai; Regemu, ati Jotamu, ati Geṣamu, ati Peleti, ati Efa, ati Ṣaafu.
48 Maaka obirin Kalebu bi Ṣeberi, ati Tirhana.
49 On si bi Ṣaafa baba Madmana, Ṣefa baba Makbena, ati baba Gibea: ọmọbirin Kalebu si ni Aksa.
50 Wọnyi li awọn ọmọ Kalebu ọmọ Huri, akọbi Efrata; Ṣobali baba Kirat-jearimu,

Digitized by Google

51 Salma baba Bet-lehemu, Harefu baba
Bet-gaderi.
52 Ati Ṣobali baba Kirjat-jearimu ni
ọmọ; Haroe, ati idaji awọn ara Manaheti.
53 Ati awọn idile Kirjat-jearimu; awọn
ara Itri, ati awọn ara Puti, ati awọn ara
Ṣummati, ati awọn ara Misrai; lọdọ wọn
li awọn ara Sareati, ati awọn ara Ẹstauli
ti wá.
54 Awọn ọmọ Salma; Betlehemu, ati
awọn ara Netofati, Ataroti, ile Joabu, ati
idaji awọn ara Manahati, awọn ara Sori.
55 Ati idile awọn akọwe ti ngbe Jabesi;
awọn ara Tira, awọn ara Ṣimeati, ati awọn
ara Sukati. Wọnyi li awọn ara Keni ti o
ti ọdọ Hemati wá, baba ile Rekabu.

## ORI 3.

WỌNYI li awọn ọmọ Dafidi, ti a bi fun
u ni Hebroni; abọbi Amnoni, lati
ọdọ Ahinoamu ara Jesreeli; ekeji Danieli,
lati ọdọ Abigaili ara Karmeli.
2 Ẹkẹta, Absalomu ọmọ Maaka ọmọbirin
Talmai ọba Gesuri; ẹkerin, Adonijah ọmọ
Haggiti.
3 Ẹkarun, Ṣefatiah lati ọdọ Abitali;
ẹkẹfa Itreamu lati ọdọ Ẹgla aya rè.
4 Awọn mẹfa wọnyi li a bi fun u ni
Hebroni; nibẹ li o si jọba li ọdun meje
on oṣù mẹfa: ati ni Jerusalemu li o jọba
li ọdun mẹtalelọgbọn.
5 Wọnyi li a si bi fun u ni Jerusalemu;
Ṣimea, ati Ṣobabu, ati Natani, ati Solo-
moni, mẹrin, lati ọdọ Batṣua ọmọbirin
Ammieli:
6 Abhari pẹlu, ati Eliṣama, ati Elifeleti,
7 Ati Noga, ati Nefegi, ati Jafia,
8 Ati Eliṣama, ati Eliada, ati Elifeleti
mẹsan.
9 Wọnyi ni gbogbo awọn ọmọ Dafidi,
laika awọn ọmọ àle rẹ̀, ati Tamari arabirin
wọn.
10 Ọmọ Solomoni si ni Rehoboamu,
Abia ọmọ rẹ̀, Asa ọmọ rẹ̀, Jehoṣafati ọmọ rẹ̀.
11 Joramu ọmọ rẹ̀, Ahasiah ọmọ rẹ̀,
Joasi ọmọ rẹ̀,
12 Amasiah ọmọ rẹ̀, Asariah ọmọ rẹ̀,
Jotamu ọmọ rẹ̀,
13 Ahasi ọmọ rẹ̀, Hesekiah ọmọ rẹ̀,
Manasse ọmọ rẹ̀,
14 Amoni ọmọ rẹ̀, Josiah ọmọ rẹ̀.
15 Ati awọn ọmọ Josiah; akọbi Joha-
nani, ekeji Jehoiakimu, ẹkẹta Sedekiah,
ẹkẹrin Ṣallumu.
16 Ati awọn ọmọ Jehoiakimu: Jekoniah
ọmọ rẹ̀, Sedekiah ọmọ rẹ̀,
17 Ati awọn ọmọ Jekoniah; Assiri,
Salatieli ọmọ rẹ̀.
18 Malkiramu pẹlu, ati Pedaiah, ati
Ṣenasari, Jekamiah, Hoṣama ati Nehabiah,
19 Ati awọn ọmọ Pedaiah; Serubba-
beli; ati Ṣimei; ati awọn ọmọ Serubbabeli;
Meṣullamu, ati Hananiah, ati Ṣelomiti
arabirin wọn:
20 Ati Haṣuba, ati Oheli, ati Berekiah,
ati Hasadiah, Juṣab-hesedi, marun.
21 Ati awọn ọmọ Hananiah; Pelatiah,
ati Jesaiah: awọn ọmọ Refaiah, awọn ọmọ
Arnani, awọn ọmọ Obadiah awọn ọmọ
Ṣekaniah.
22 Ati awọn ọmọ Ṣekaniah; Ṣemaiah;
ati awọn ọmọ Ṣemaiah; Hettuṣi, ati Ige-
ali, ati Bariah, ati Neariah, ati Ṣafati, mẹfa.
23 Ati awọn ọmọ Neariah; Elioenai,
ati Hesekiah, ati Asrikamu, mẹta.
24 Ati awọn ọmọ Elioenai ni, Hodaiah,
ati Eliaṣibu, ati Pelaiah, ti Akkubu, ati
Johanani, ati Dalaiah, ati Anani, meje.

## ORI 4.

AWỌN ọmọ Juda; Faresi, Hesroni, ati
Karmi, ati Huri, ati Ṣobali.
2 Reaiah ọmọ Ṣobali si bi Jahati; Ja-
hati si bi Ahumai, ati Lahadi. Wọnyi ni
idile awọn ara Sora.
3 Awọn wọnyi li o ti ọdọ baba Etamu
wá; Jesreeli ati Jisma, ati Jidbaṣi: orukọ
arabirin wọn si ni Selelponi:
4 Ati Penueli ni baba Gedori, ati Eseri
baba Huṣa. Wọnyi ni awọn ọmọ Huri,
akọbi Efrata, baba Betlehemu.
5 Aṣuri baba Tekoa si li aya meji, Hela
ati Naara.
6 Naara si bi Ahusamu, ati Heferi, ati
Temeni, ati Ahaṣtari fun u. Wọnyi li
awọn ọmọ Naara.
7 Ati awọn ọmọ Hela ni Sereti, ati
Jesoari, ati Etnani.
8 Kosi si bi Anubu, ati Sobeba, ati awọn
idile Aharheli, ọmọ Harumu.
9 Jabesi si ṣe ọlọla jù awọn arakọnrin
rẹ̀ lọ: iya rẹ̀ si pe orukọ rẹ̀ ni Jabesi, wipe,
Nitoriti mo bi i pẹlu ibanujẹ.
10 Jabesi si ké pè Ọlọrun Israeli, wipe,
Iwọ iba jẹ bukún mi nitõtọ, ki o si sọ
àgbegbe mi di nla, ki ọwọ rẹ ki o si wà
pẹlu mi, ati ki iwọ ki o má si jẹ ki emi
ri ibi, ki emi má si ri ibinujẹ! Ọlọrun si
mu ohun ti o tọrọ ṣẹ.
11 Kelubu arakọnrin Ṣua si bi Mehiri,
ti iṣe baba Eṣtoni.
12 Eṣtoni si bi Bet-rafa, ati Pasea, ati

Digitized by Google

Tehinna baba ilu Nahaṣi. Wọnyi li awọn
ọkọnrin Reka,
13 Ati awọn ọmọ Kenasi; Otnieli, ati
Seraiah: ati awọn ọmọ Otnieli; Hatati.
14 Meonotai si bi Ofra: Seraiah si bi
Joabu, baba Geharasimu; nitori oniṣọnà
ni nwọn.
15 Ati awọn ọmọ Kalebu ọmọ Jefunne;
Iru, Ela, ati Naamu: ati awọn ọmọ Ela,
ani Kenasi.
16 Ati awọn ọmọ Jehaleleeli; Sifu, ati
Sifa, Tiria, ati Asareeli.
17 Ati awọn ọmọ Esra ni Jeteri, ati
Meredi, ati Eferi, ati Jaloni: on si bi
Miriamu, ati Ṣammai, ati Iṣba baba Eṣte-
moa.
18 Aya rẹ̀ Jehudijah si bi Jeredi baba
Gedori, ati Heberi baba Soke, ati Jedutieli
baba Sanoa. Wọnyi si li awọn ọmọ Bitiah
ọmọbirin Farao ti Meredi mu li aya.
19 Ati awọn ọmọ aya Hodiah, arabirin
Nahamu, baba Keila, ara Garmi, ati Eṣte-
moa ara Maaka.
20 Awọn ọmọ Ṣimoni si ni Amnoni, ati
Rinna, Benhanani, ati Tiloni. Ati awọn
ọmọ Iṣi ni, Soheti, ati Bensoheti,
21 Awọn ọmọ Ṣela, ọmọ Juda ni, Eri
baba Leka, ati Laada baba Mareṣa ati idile
ile awọn ti nwọn nwun aṣọ ọ̀gbọ daradara,
ti ile Aṣbea,
22 Ati Jokimu, ati awọn ọkọnrin Ko-
seba, ati Joaṣi, ati Sarafu, ti o ni ijọba ni
Moabu, ati Jaṣubilehemu. Iwe iranti atijọ
ni wọnyi.
23 Wọnyi li awọn amọkoko, ati awọn
ti ngbe ãrin ọgba ti odi yika; nibẹ ni nwọn
ngbe pẹlu ọba fun iṣẹ rẹ̀.
24 Awọn ọmọ Simeoni ni, Nemueli, ati
Jamini, Jaribi, Sera, Ṣauli:
25 Ṣallumu ọmọ rẹ̀, Mibsamu ọmọ rẹ̀,
Miṣma ọmọ rẹ̀.
26 Ati awọn ọmọ Miṣma; Hammueli
ọmọ rẹ̀, Sakkuri ọmọ rẹ̀, Ṣimei ọmọ rẹ̀.
27 Ṣimei si ni ọmọkọnrin mẹrindilogun,
ati ọmọbirin mẹfa; ṣugbọn awọn arakọn-
rin rẹ̀ kò ni ọmọkọnrin pupọ, bẹ̃ni kì iṣe
idile wọn gbogbo li o rẹ̀ gẹgẹ bi awọn ọmọ
Juda.
28 Nwọn si ngbe Beersẹba, ati Molada,
ati Haṣari-ṣuali,
29 Ati ni Bilha, ati ni Esemu, ati ni
Toladi,
30 Ati ni Betueli, ati ni Horma, ati ni
Siklagi,
31 Ati ni Bet-markaboti, ati ni Hasar-
susimu, ati ni Bet-birei, ati Ṣaaraimu.
Awọn wọnyi ni ilu wọn, titi di ijọba
Dafidi.
32 Ileto wọn si ni, Etamu, ati Aini,
Rimmoni, ati Tokeni, ati Aṣani, ilu
marun:
33 Ati gbogbo ileto wọn, ti o wà yi ilu
na ka, de Baali. Wọnyi ni ibugbe wọn,
ati itan idile wọn.
34 Ati Meṣobabu ati Jamleki, ati Joṣa
ọmọ Amasiah.
35 Ati Joeli, ati Jehu ọmọ Josibiah, ọmọ
Seraiah, ọmọ Asieli,
36 Ati Elioenai, ati Jaakoba, ati Jeṣo-
haiah, ati Asaiah, ati Adieli, ati Jesimieli,
ati Benaiah,
37 Ati Sisa ọmọ Ṣifi, ọmọ Alloni, ọmọ
Jedaiah, ọmọ Ṣimri ọmọ Ṣemaiah;
38 Awọn ti a darukọ wọnyi, ìjoye ni nwọn
ni idile wọn: ile baba wọn si tan kalẹ
gidigidi.
39 Nwọn si wọ̀ oju-ọ̀na Gedori lọ, titi
de apa ariwa afonifoji na, lati wá koriko
fun agbo-ẹran wọn.
40 Nwọn si ri koriko tutù ti o si dara;
ilẹ na si gbàye, o si gbe jẹ, o si wà li ala-
fia: nitori awọn ọmọ Hamu li o ti ngbe ibẹ
li atijọ.
41 Ati awọn wọnyi ti a kọ orukọ wọn,
dé li ọjọ Hesekiah ọba Juda, nwọn si kọlu
agọ wọn, ati pẹlu awọn ara Mehuni ti a ri
nibẹ, nwọn si bà wọn jẹ patapata titi di
oni yi, nwọn si ngbe ipò wọn: nitori kori-
ko mbẹ nibẹ fun agbo ẹran wọn.
42 Omiran ninu wọn, ani ninu awọn
ọmọ Simeoni, ẹ̃dẹgbẹta ọkọnrin, lọ si òke
Seiri, nwọn ni Pelatiah, ati Neariah, ati
Refaiah ati Ussieli, awọn ọmọ Iṣi li olori
wọn.
43 Nwọn si kọlù iyokù awọn ara Ama-
leki, ti nwọn salà, nwọn si ngbe ibẹ titi
di oni yi.

## ORI 5.

NJẸ awọn ọmọ Reubeni, akọbi Israeli,
(nitori on li akọbi; ṣugbọn, bi o ti
ṣepe o ba ẹní baba rẹ̀ jẹ, a fi ogun ibi rẹ̀
fun awọn ọmọ Josefu ọmọ Israeli: a kì yio
si ka itan-idile na gẹgẹ bi ipò ibi.
2 Nitori Juda bori awọn arakọnrin rẹ̀,
ati lọdọ rẹ̀ ni alaṣẹ ti jade wá; ṣugbọn
ogún ibi jẹ ti Josefu:)
3 Mo ni, awọn ọmọ Rubeni akọbi Israeli
ni Hanoku, ati Pallu, Hesroni, ati Karmi.
4 Awọn ọmọ Joeli; Ṣemaiah ọmọ rẹ̀,
Gogu ọmọ rẹ̀, Ṣimei ọmọ rẹ̀,

Digitized by Google

5 Mika ọmọ rẹ̀, Reaiah ọmọ rẹ̀, Baali
ọ rẹ̀,
6 Beera ọmọ rẹ̀, ti Tiglat-pilneseri ọba
siria kò ni ìgbekun lọ; ijoye awọn ọmọ
beni ni iṣe.
7 Ati awọn arakọnrin rẹ̀ nipa idile wọn,
gbati a nkà itàn-idile iran wọn, Jeieli,
Sekariah ni olori.
8 Ati Bela ọmọ Asasi, ọmọ Ṣema, ọmọ
eli, ti ngbe Aroeri, ani titi de Nebo ati
almeoni:
9 Ati niha ariwa, o tẹ̀do lọ titi de ati-
aginju lati odò Eufrate; nitoriti ẹran
n wọn pọ̀ si i ni ilẹ Gileadi.
10 Ati li ọjọ Ṣauli, nwọn ba awọn ọmọ
gari jagun, ẹniti o ṣubu nipa ọwọ wọn:
ọn si ngbe inu agọ wọn ni gbogbo ilẹ
wa Gileadi.
11 Ati awọn ọmọ Gadi ngbe ọkánkan
n, ni ilẹ Baṣani titi de Salka:
12 Joeli olori, ati Ṣafamu àtẹle, ati
anai, ati Ṣafati ni Baṣani.
13 Ati awọn arakọnrin wọn ti ile awọn
ba wọn ni Mikaeli, ati Meṣullamu, ati
ba, ati Jorai, ati Jakani, ati Sia, ati
eberi, meje.
14 Wọnyi li awọn ọmọ Abihaili, ọmọ
uri, ọmọ Jaroa, ọmọ Gileadi, ọmọ Mika-
, ọmọ Jeṣiṣai, ọmọ Jado, ọmọ Busi;
15 Adi, ọmọ Abdieli, ọmọ Guni, olori
awọn baba wọn.
16 Nwọn si ngbe Gileadi ni Baṣani, ati
nu awọn ilu rẹ̀, ati ninu gbogbo igbe-
ko Ṣaroni, li àgbegbe wọn.
17 Gbogbo wọnyi li a kà nipa ítanidile,
ọjọ Jotamu ọba Juda, ati li ọjọ Jerobo-
nu ọba Israeli,
18 Awọn ọmọ Reubeni, ati awọn ọmọ
adi, ati àbọ ẹ̀ya Manasse, ninu awọn ọkọn-
n alagbara ti nwọn ngbé asà ati idà, ti
wọn si nfi ọrun tafà, ti nwọn si mòye
gun, jẹ ọkẹ meji enia o le ẹgbẹrinlelogún
di ogoji, ti o jade lọ si ogun na.
19 Nwọn si ba awọn ọmọ Hagari jagun,
ẹlu Jeturi, ati Nefiṣi ati Nadabu.
20 A si ràn wọn lọwọ si wọn, a si fi
wọn ọmọ Hagari le wọn lọwọ, ati gbogbo
wọn ti o wà pẹlu wọn: nitoriti nwọn
epè Ọlọrun li ogun na, on si gbọ́ ẹ̀bẹ wọn;
itoriti nwọn gbẹkẹ wọn le e.
21 Nwọn si kó ẹran-ọ̀sin wọn lọ; iba-
asiẹ ẹgbãmẹ̃dọgbọ̀n ati àgutan ọkẹ mejila
le ẹgbãrun, ati kẹtẹkẹtẹ ẹgbã, ati enia
kẹ marun.
22 Nitori ọ̀pọlọpọ li o ṣubu ti a pa, ni-
ori lati ọdọ Ọlọrun li ogun na. Nwọn si
joko ni ipò wọn titi di igbà ikolọ si ìgbe-
kun.
23 Awọn ọmọkọnrin àbọ ẹ̀ya Manasse
joko ni ilẹ na: nwọn bi si i lati Baṣani titi
de Baal-hermoni, ati Seniri, ati titi de òke
Hermoni.
24 Wọnyi si li awọn olori ile awọn baba
wọn, Eferi, ati Iṣi, ati Elieli, ati Asrieli,
ati Jeremiah, ati Hodafiah, ati Jahdieli,
awọn alagbara akọni ọkọnrin, ọkọnrin olo-
kiki, ati olori ile awọn baba wọn.
25 Nwọn si ṣẹ̀ si Ọlọrun awọn baba wọn,
nwọn si ṣe àgbere tọ awọn ọlọrun enia ilẹ
na lẹhin, ti Ọlọrun ti parun ni iwaju wọn.
26 Ọlọrun Israeli rú ẹmi Pulu ọba Assi-
ria soke, ati ẹmi Tiglat-pilneseri ọba Assi-
ria, on si kó wọn lọ, ani awọn ọmọ Reubeni
ati awọn ọmọ Gadi, ati àbọ ẹ̀ya Manasse,
o si kó wọn wá si Hala, ati Habori, ati
Hara, ati si odò Goṣani, titi di oni yi.

## ORI 6.

AWỌN ọmọ Lefi; Gerṣoni, Kohati, ati
Merari.
2 Ati awọn Kohati; Amramu, Ishari,
ati Hebroni, ati Ussieli.
3 Ati awọn Amramu; Aaroni, ati Mose,
ati Miriamu. Awọn ọmọ Aaroni; Nada-
bu, ati Abihu, Eleasari, ati Itamari.
4 Eleasari bi Finehasi, Finehasi si bi
Abiṣua,
5 Abiṣua si bi Bukki, Bukki si bi Ussi,
6 Ussi si bi Serahiah, Serahiah si bi
Meraioti,
7 Meraioti bi Amariah, Amariah si bi
Ahitubu.
8 Ahitubu si bi Sadoki, Sadoki si bi
Ahimaasi,
9 Ahimaasi si bi Asariah, Asariah si bi
Johanani,
10 Johanani si bi Asariah (on na li ẹniti
nṣiṣẹ alufa ni tempili ti Solomoni kọ́ ni
Jerusalemu;)
11 Asariah si bi Amariah, Amariah si
bi Ahitubu,
12 Ahitubu si bi Sadoki, Sadoki si bi
Ṣallumu,
13 Ṣallumu si bi Hilkiah, Hilkiah si bi
Asariah,
14 Asariah si bi Seraiah, Seraiah si bi
Jehosadaki,
15 Jehosadaki si lọ si oko-ẹrú, nigbati
Oluwa kó Juda ati Jerusalemu lọ nipa ọwọ
Nebukadnessari.
16 Awọn ọmọ Lefi; Gersọmu, Kohati,
ati Merari.

Digitized by Google

17 Wọnyi si li orukọ awọn ọmọ Gerṣomu, Libni, ati Ṣimei.
18 Awọn ọmọ Kohati ni, Amramu, ati Ishari, ati Hebroni, ati Ussieli.
19 Awọn ọmọ Merari; Mahli ati Muṣi.
Wọnyi si ni idile awọn ọmọ Lefi, gẹgẹ bi awọn baba wọn.
20 Ti Gerṣomu; Libni ọmọ rẹ̀, Jahati ọmọ rẹ̀, Simma ọmọ rẹ̀.
21 Joa ọmọ rẹ̀, Iddo ọmọ rẹ̀, Sera ọmọ rẹ̀, Jeaterai ọmọ rẹ̀.
22 Awọn ọmọ Kohati; Amminadabu ọmọ rẹ̀, Kora ọmọ rẹ̀, Assiri ọmọ rẹ̀.
23 Elkana ọmọ rẹ̀, ati Ebiasafu ọmọ rẹ̀, ati Assiri ọmọ rẹ̀,
24 Tahati ọmọ rẹ̀, Urieli ọmọ rẹ̀, Ussiah ọmọ rẹ̀, ati Ṣaulu ọmọ rẹ̀,
25 Ati awọn ọmọ Elkana; Amasai, ati Ahimoti.
26 Niti Elkana: awọn ọmọ Elkana; Sofai ọmọ rẹ̀, ati Nahati ọmọ rẹ̀,
27 Eliabu ọmọ rẹ̀, Jerohamu ọmọ rẹ̀, Elkana ọmọ rẹ̀.
28 Awọn ọmọ Samueli; akọbi Faṣni, ati Abiah.
29 Awọn ọmọ Merari; Mahli, Libni, ọmọ rẹ̀, Ṣimei ọmọ rẹ̀, Ussa ọmọ rẹ̀,
30 Ṣimea ọmọ rẹ̀, Haggiah ọmọ rẹ̀, Asaiah ọmọ rẹ̀.
31 Wọnyi si ni awọn ti Dafidi yàn ṣe ọlori iṣẹ orin ni ile Oluwa, lẹhin igbati apoti-ẹri Oluwa ti ni isimi.
32 Nwọn si nfi orin ṣe isin niwaju ibugbe agọ ajọ, titi Solomoni fi kọ́ ile Oluwa ni Jerusalemu tan: nwọn si duro ti iṣe òye wọn gẹgẹ bi ipa wọn.
33 Wọnyi si li awọn ti o duro pẹlu awọn ọmọ wọn. Ninu awọn ọmọ Kohati: Hemani akọrin, ọmọ Joeli, ọmọ Samueli,
34 Ọmọ Elkana, ọmọ Jerohamu, ọmọ Elieli, ọmọ Toha,
35 Ọmọ Sufu, ọmọ Elkana, ọmọ Mahati, ọmọ Amasai,
36 Ọmọ Elkana, ọmọ Joeli, ọmọ Asariah, ọmọ Sefaniah,
37 Ọmọ Tahati, ọmọ Assiri, ọmọ Ebiasafu, ọmọ Kora,
38 Ọmọ Ishari, ọmọ Kohati, ọmọ Lefi, ọmọ Israeli.
39 Ati arakọnrin rẹ̀ Asafu, ti o duro li ọwọ ọ̀tun rẹ̀, ani Asafu, ọmọ Berakiah, ọmọ Ṣimea,
40 Ọmọ Mikaeli, ọmọ Baaseiah, ọmọ Malkiah.
41 Ọmọ Etni, ọmọ Sera, ọmọ Adaiah,
42 Ọmọ Etani, ọmọ Simma, ọmọ Ṣimei,
43 Ọmọ Jahati, ọmọ Gerṣomu, ọmọ Lefi.
44 Awọn arakọnrin wọn, awọn ọmọ Merari duro lọwọ osi: Etani ọmọ Kiṣi, ọmọ Abdi, ọmọ Malluku,
45 Ọmọ Haṣabiah, ọmọ Amasiah, ọmọ Hilkiah,
46 Ọmọ Amsi, ọmọ Bani, ọmọ Ṣameri.
47 Ọmọ Mahli, ọmọ Muṣi, ọmọ Merari, ọmọ Lefi,
48 Arakọnrin wọn pẹlu, awọn ọmọ Lefi, li a yàn si oniruru iṣẹ gbogbo ti agọ ile Ọlọrun.
49 Ṣugbọn Aaroni ati awọn ọmọ rẹ̀ nrubọ lori pẹpẹ ẹbọ sisun, ati lori pẹpẹ turari, a si yàn wọn si gbogbo iṣẹ ibi mimọ́-jùlọ, ati lati ṣe ètutu fun Israeli, gẹgẹ bi gbogbo eyi ti Mose, iranṣẹ Ọlọrun, ti pa li aṣẹ.
50 Wọnyi si li awọn ọmọ Aarọni; Eleasari ọmọ rẹ̀, Finehasi ọmọ rẹ̀, Abiṣua ọmọ rẹ̀,
51 Bukki ọmọ rẹ̀, Ussi ọmọ rẹ̀, Serahiah ọmọ rẹ̀,
52 Meraioti ọmọ rẹ̀, Amariah ọmọ rẹ̀, Ahitubu ọmọ rẹ̀,
53 Sadoku ọmọ rẹ̀, Ahimaasi ọmọ rẹ̀.
54 Wọnyi si ni ibùgbe wọn gẹgẹ bi budo wọn li àgbegbe wọn, ti awọn ọmọ Aaroni, ti idile awọn ọmọ Kohati: nitori ti wọn ni ipin ikini.
55 Nwọn si fun wọn ni Hebroni ni ilẹ Juda, ati ìgberiko rẹ̀ yi i kakiri.
56 Ṣugbọn oko ilu na, ati ileto wọn, ni nwọn fun Kalebu ọmọ Jefunne.
57 Nwọn si fi ilu Juda fun awọn ọmọ Aaroni, ani Hebroni, ilu àbo ati Libna pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Jattiri, ati Eṣtemoa, pẹlu ìgberiko wọn,
58 Ati Hileni pẹlu ìgberiko rẹ̀, Debiri pẹlu ìgberiko rẹ̀,
59 Ati Aṣani pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Betṣemeṣi pẹlu ìgberiko rẹ̀:
60 Ati lati inu ẹ̀ya Benjamini; Geba pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Alemeti pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Anatoti pẹlu ìgberiko rẹ̀. Gbogbo ilu wọn ni idile wọn jẹ ilu mẹtala.
61 Ati fun awọn ọmọ Kohati, ti o kù ni idile ẹ̀ya na, li a fi keké fi ilu mẹwa fun, ninu àbọ ẹ̀ya, ani lati inu àbọ ẹ̀ya Manasse.
62 Ati fun awọn ọmọ Gerṣomu ni idile wọn, lati inu ẹ̀ya Issakari, ati inu ẹ̀ya Aṣeri, ati lati inu ẹ̀ya Naftali, ati lati inu ẹ̀ya Manasse ni Baṣani, ilu mẹtala.
63 Fun awọn ọmọ Merari ni idile wọn li a fi keké fi ilu mejila fun, lati inu ẹ̀ya

Digitized by Google

Reubeni, ati lati inu ẹ̀ya Gadi, ati lati inu
ẹ̀ya Sebuluni,
64 Awọn ọmọ Israeli fi ilu wọnyi fun
awọn ọmọ Lefi pẹlu ìgberiko wọn.
65 Nwọn si fi keké fi ilu wọnyi ti a da
orukọ wọn fun ni lati inu ẹ̀ya awọn ọmọ
Juda, ati lati inu ẹ̀ya awọn ọmọ Simeoni,
ati lati inu ẹ̀ya awọn ọmọ Benjamini.
66 Ati iyokù ninu idile awọn ọmọ Ko-
hati ni ilu li àgbegbe wọn lati inu ẹ̀ya
Efraimu.
67 Nwọn si fi ninu ilu àbo fun wọn,
Ṣekemu li òke Efraimu pẹlu ìgberiko rẹ̀;
Geseri pẹlu ìgberiko rẹ̀,
68 Ati Jokneamu pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati
Bet-horoni pẹlu ìgberiko rẹ̀,
69 Ati Aijaloni pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati
Gatrimmoni pẹlu ìgberiko rẹ̀:
70 Ati lati inu àbọ ẹ̀ya Manasse; Aneri
pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Bileamu pẹlu ìgberiko
rẹ̀, fun idile awọn ọmọ Kohati iyokù.
71 Awọn ọmọ Gerṣomu lati inu idile àbọ
ẹ̀ya Manasse li a fi Golani ni Baṣani fun
pẹlu ìgberiko rẹ̀; ati Aṣtaroti pẹlu igbe-
riko rẹ̀,
72 Ati lati inu ẹ̀ya Issakari; Kadeṣi
pẹlu ìgberiko rẹ̀; Daberati pẹlu ìgberiko
rẹ̀,
73 Ati Ramoti pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Ane-
mu pẹlu ìgberiko rẹ̀:
74 Ati lati inu ẹ̀ya Aṣeri; Maṣali pẹlu
ìgberiko rẹ̀, ati Abdoni pẹlu ìgberiko rẹ̀.
75 Ati Hakoku pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati
Rehobu pẹlu ìgberiko rẹ̀:
76 Ati lati inu ẹ̀ya Naftali; Kedeṣi ni
Galili pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Hammoni pẹlu
ìgberiko rẹ̀, ati Kirjataimu pẹlu ìgberiko
rẹ̀.
77 Fun iyokù awọn ọmọ Merari li a fi
Rimmoni pẹlu ìgberiko rẹ̀ fun, Tabori pẹlu
ìgberiko rẹ̀, lati inu ẹ̀ya Sebuluni:
78 Ati li apa keji Jordani leti Jeriko, ni
iha ariwa Jordani, li a fi Beseri li aginju
pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Jasa pẹlu ìgberiko rẹ̀
fun wọn, lati inu ẹ̀ya Reubeni,
79 Ati Kedemoti pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati
Mefaati pẹlu ìgberiko rẹ̀:
80 Ati lati inu ẹ̀ya Gabi, Ramoti ni
Gileadi pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati Mahanaimu
pẹlu ìgberiko rẹ̀.
81 Ati Heṣboni pẹlu ìgberiko rẹ̀, ati
Jaseri pẹlu ìgberiko rẹ̀.

## ORI 7.

AWỌN ọmọ Issakari si ni, Tola, ati Pua,
Jaṣubu, ati Ṣimroni, mẹrin.
2 Ati awọn ọmọ Tola; Ussi, ati Refaiah,
ati Jerieli, ati Jamai, ati Jibsamu ati Samu-
eli, awọn olori ile baba wọn, eyini ni ti
Tola: akọni alagbara enia ni nwọn ni iran
wọn; iye awọn ẹniti o jẹ ẹgbã mọkanla o
le ẹgbẹta li ọjọ Dafidi.
3 Awọn ọmọ Ussi: Israhiah ati awọn
ọmọ Israhiah; Mikaeli, ati Obadiah, ati
Joeli, ati Iṣiah, marun: gbogbo wọn li
olori.
4 Ati pẹlu wọn, nipa iran wọn, gẹgẹ bi
ile baba wọn, ni awọn ẹgbẹ ọmọ-ogun fun
ogun, ẹgbã mejidilogun enia: nitoriti nwọn
ni òpọlọpọ obirin ati ọmọ ọkọnrin.
5 Ati awọn arakọnrin wọn ninu gbogbo
idile Issakari jẹ akọni alagbara enia, ni ki-
kaye gbogbo wọn nipa iran wọn, nwọn jẹ
ẹgbamẹtalelogoji o le ẹgbẹrun.
6 Awọn ọmọ Benjamini: Bela, ati Be-
keri, ati Jediaeli, mẹta.
7 Awọn ọmọ Bela; Esboni, ati Ussi, ati
Ussieli ati Jerimoti ati Iri, marun; awọn
olori ile baba wọn, akọni alagbara enia; a
si kaye wọn nipa iran wọn si ẹgbãmọkanla
enia o le mẹrinlelọgbọn.
8 Awọn ọmọ Bekeri: Semira, ati Joaṣi,
ati Elieseri, ati Elioeni, ati Omri, ati Jere-
motu, ati Abiah, ati Anatoti, ati Alameti.
Gbogbo wọnyi li awọn ọmọ Bekeri.
9 Ati iye wọn, ni idile wọn nipa iran
wọn, awọn olori ile baba wọn, akọni ala-
gbara enia, jẹ ẹgbawa o le igba.
10 Awọn ọmọ Jediaeli; Bilhani: ati
awọn ọmọ Bilhani: Jeuṣi, ati Benjamini,
ati Ehudi, ati Kenaana, ati Setani, ati
Tarṣiṣi ati Ahisahari.
11 Gbogbo awọn wọnyi ọmọ Jediaeli,
nipa olori awọn baba wọn, akọni alagbara
enia, jẹ ẹgbãjọ o le ẹgbẹfa ọmọ-ogun, ti o
le jade lọ si ogun.
12 Ati Ṣuppimu, ati Huppimu, awọn
ọmọ Iri, ati Huṣimu, awọn ọmọ Aheri.
13 Awọn ọmọ Naftali: Jasieli, ati Guni,
ati Jeseri, ati Ṣallumu, awọn ọmọ Bilha.
14 Awọn ọmọ Manasse; Aṣrieli, ti aya
rẹ̀ bi: (ṣugbọn obirin rẹ̀, ara Aramu, bi
Makiri baba Gileadi:
15 Makiri si mu arabirin Huppimu, ati
Ṣuppimu li aya, orukọ arabirin ẹniti ijẹ
Maaka,) ati orukọ ekeji ni Selofehadi:
Selofehadi si ni awọn ọmọbirin.
16 Maaka, obirin Makiri, bi ọmọ, on si
pe orukọ rẹ̀ ni Pereṣi: orukọ arakọnrin rẹ̀
ni Ṣereṣi; ati awọn ọmọ rẹ̀ ni Ulamu ati
Rakemu.
17 Awọn ọmọ Ulamu: Bedani. Awọn

Digitized by Google

wọnyi li awọn ọmọ Gileadi, ọmọ Makiri,
ọmọ Manasse.
18 Arabirin rẹ̀, Hammoleketi, bi Iṣodi,
ati Abioseri, ati Mahala.
19. Ati awọn ọmọ Ṣemida ni, Ahiani, ati
Ṣekemu, ati Likki, ati Aniamu.
20 Awọn ọmọ Efraimu: Ṣutela, ati Be-
redi ọmọ rẹ̀, ati Tahati, ọmọ rẹ̀, ati Elada,
ọmọ rẹ̀, ati Tahati ọmọ rẹ̀.
21 Ati Sabadi ọmọ rẹ̀, ati Ṣutela ọmọ rẹ̀,
ati Eseri, ati Eleadi, ẹniti awọn ọkọnrin
Gati, ti a bi ni ilẹ na, pa, nitori nwọn
sọkalẹ wá lati kó ẹran-ọ̀sin wọn lọ.
22 Efraimu baba wọn si ṣọ̀fọ, li ọjọ pupọ,
awọn arakọnrin rẹ̀ si wá lati tù u ninu.
23 Nigbati o si wọle tọ̀ aya rẹ̀ lọ, o lo-
yun o si bi ọmọ kan, on si pè orukọ rẹ̀ ni
Beria, nitoriti ibi ba ile rẹ̀.
24 Ọmọ rẹ̀ obirin ni Sera, ẹniti o tẹ̀ Bet-
horoni dó, ti isalẹ ati ti òke, ati Usseni
Ṣera.
25 Refa si ni ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, Reṣefu
pẹlu, ati Tela ọmọ rẹ̀, ati Tahani ọmọ rẹ̀.
26 Laadani ọmọ rẹ̀, Ammihudi ọmọ rẹ̀,
Eliṣama ọmọ rẹ̀.
27 Nuni ọmọ rẹ̀, Jọsua ọmọ rẹ̀.
28 Ati awọn ini ati ibugbe wọn ni Be-
teli, ati ilu rẹ̀, ati niha ìla-õrùn Naarani,
niha ìwọ-õrùn Geseri pẹlu ilu rẹ̀: Ṣekemu
pẹlu ati ilu rẹ̀, titi de Gasa ilu rẹ̀:
29 Ati leti ilu awọn ọmọ Manasse, Betṣe-
ani, ati ilu rẹ̀, Taanaki ati ilu rẹ̀, Megiddo
ati ilu rẹ̀, Dori ati ilu rẹ̀. Ninu awọn
wọnyi li awọn ọmọ Josefu, ọmọ Israeli,
ngbe.
30 Awọn ọmọ Aṣeri: Imna, ati Iṣua,
ati Iṣuai, ati Beria, ati Sera, arabirin wọn.
31 Awọn ọmọ Beria: Heberi, ati Malki-
eri, ti iṣe baba Birsafiti.
32 Heberi si bi Jafleti, ati Ṣomeri, ati
Hotamu, ati Ṣua, arabirin wọn.
33 Ati awọn ọmọ Jafleti: Pasaki, ati
Bimhali, ati Aṣfati. Wọnyi li awọn ọmọ
Jafleti.
34 Awọn ọmọ Sameri: Ahi, ati Roga,
Jehubba, ati Aramu.
35 Awọn ọmọ arakọnrin rẹ̀ Helemu:
Sofa, ati Imna, ati Ṣeleṣi, ati Amali.
36 Awọn ọmọ Sofa: Sua, ati Harneferi,
ati Ṣuali, ati Beri, ati Imra,
37 Beseri, ati Hodi, ati Ṣamma, ati
Ṣilṣa, ati Itrani, ati Beera.
38 Ati awọn ọmọ Jeteri; Jefunne, ati
Pispa, ati Ara.
39 Ati awọn ọmọ Ulla: Ara, ati Ha-
nieli, ati Resia.
40 Gbogbo awọn wọnyi li awọn ọmọ
Aṣeri, awọn olori ile baba wọn, aṣayan ala-
gbara akọni enia, olori ninu awọn ijoye.
Iye awọn ti a kà yẹ fun ogun, ati fun ijà
ni idile wọn jẹ, ẹgbã mẹtala ọkọnrin.

## ORI 8.

BENJAMINI si bi Bela, akọbi rẹ̀, Aṣbeli
ekeji, ati Ahara ẹkẹta,
2 Noha ẹkẹrin, ati Rafa ẹkarun.
3 Awọn ọmọ Bela ni Addari, ati Gera,
ati Abihudi,
4 Ati Abiṣua, ati Naamani, ati Ahoa,
5 Ati Gera, ati Ṣefufani, ati Huramu,
6 Wọnyi si li awọn ọmọ Ehudi: wọnyi
li awọn olori baba wọn, ti nwọn ngbe
Geba, nwọn si ko wọn lọ si Mahanati ni
igbekun.
7 Ati Naamani, ati Ahiah, ati Gera, o
si ko wọn kuro, o si bi Ussa ati Alihudi.
8 Ṣaharaimu si bi ọmọ ni ilẹ Moabu;
lẹhin igbati o ti ran wọn lọ tan; Huṣimu
ati Baera si li awọn aya rẹ̀.
9 Hodeṣi, aya rẹ̀, si bi Jobabu, ati
Sibia, ati Meṣa, ati Malkama fun u,
10 Ati Jeusi, ati Ṣokia, ati Mirma.
Wọnyi li awọn ọmọ rẹ̀, olori awọn baba.
11 Huṣimu si bi Ahitubu ati Elpaali
fun u.
12 Awọn ọmọ Elpaali, Eberi, ati Mi-
ṣamu ati Ṣameri, ẹniti o kọ́ Ono ati Lodi
pẹlu ilu wọn:
13 Beria pẹlu, ati Ṣema, ti nwọn iṣe
olori awọn baba awọn ara Ajaloni, awọn ti
o le awọn ara Gati kuro.
14 Ati Ahio, Ṣaṣaki, Jerimotu,
15 Ati Sebadiah, ati Aradi, ati Aderi,
16 Ati Mikaeli, ati Ispa, ati Joha, ni
awọn ọmọ Beria;
17 Ati Sebadiah, ati Meṣullamu, ati
Heseki, ati Heberi.
18 Iṣmeri pẹlu, ati Jeslia, ati Jobabu,
ni awọn ọmọ Elpaali.
19 Ati Jakimu, ati Sikri, ati Sabdi,
20 Ati Elienai, ari Siltai, ati Elieli,
21 Ati Adaiah, ati Beraiah, ati Ṣimrati
ni awọn ọmọ Ṣimhi;
22 Ati Iṣpani, ati Eberi, ati Elieli,
23 Ati Abdoni, ati Sikri, ati Hanani,
24 Ati Hananiah, ati Elamu, ati Anto-
tiah,
25 Ati Ifediah, ati Penueli, ni awọn ọmọ
Ṣaṣaki;
26 Ati Samṣerai, ati Sehariah, ati Ata-
liah,

Digitized by Google

27 Ati Jaresiah, ati Eliah, ati Sikri, ni
awọn ọmọ Jerohamu.
28 Wọnyi li olori awọn baba, nipa iran
wọn, awọn olori. Awọn wọnyi ni ngbe
Jerusalemu.
29 Ni Gibeoni ni baba Gibeoni si ngbe;
orukọ aya ẹniti ijẹ Maaka:
30 Ọmọ rẹ̀, akọbi si ni Abdoni, ati Suri,
ati Kiṣi, ati Baali, ati Nadabu,
31 Ati Gedori, ati Ahio, ati Sakeri,
32 Mikloti si bi Ṣimea. Awọn wọnyi
pẹlu si mba awọn arakọnrin wọn gbe Jeru-
salemu, nwọn kọju si ara wọn.
33 Neri si bi Kiṣi, ati Kiṣi si bi Saulu,
ati Saulu si bi Jonatani, ati Milkiṣua, ati
Abinadabu, ati Esbaali.
34 Ọmọ Jonatani si ni Meribaali; Meri-
baali si bi Mika.
35 Awọn ọmọ Mika ni Pitoni ati Me-
leki, ati Tarea, ati Ahasi.
36 Ahasi si bi Jehoadda; ati Jehoadda
si bi Alemeti, ati Asmafeti, ati Simri:
Simri si bi Mosa;
37 Mosa si bi Binea, Rafa ọmọ rẹ̀, Elea-
sari ọmọ rẹ̀, Aseli ọmọ rẹ̀:
38 Aseli si ni ọmọkọnrin mẹfa, orukọ
wọn ni wọnyi, Asrikamu, Bokeru, ati Iṣma-
eli, ati Seraiah, ati Obadiah, ati Hanani.
Gbogbo awọn wọnyi li ọmọ Aseli.
39 Awọn ọmọ Eṣeki arakọnrin rẹ̀ si ni
Ulamu akọbi rẹ̀, Jehuṣi ekeji, ati Elifeleti
ẹkẹta.
40 Awọn ọmọ Ulamu si jẹ alagbara
akọni ọkọnrin tafatafa, nwọn si li ọmọ pupọ
ati ọmọ ọmọ adọjọ. Gbogbo wọnyi li awọn
ọmọ Benjamini.

## ORI 9.

ASI ka iye gbogbo Israeli ni idile idile
wọn; si kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe
awọn ọba Israeli: Juda li a si kó lọ si Babi-
lọni nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
2 Awọn ti o tetekọ gbe ilẹ ini wọn, ati
ilu wọn li awọn ọmọ Israeli, awọn alufa,
ati awọn ọmọ Lefi ati awọn Netinimu.
3 Ni Jerusalemu ni, ninu awọn ọmọ
Juda, ati ninu awọn ọmọ Benjamini, ati
ninu awọn ọmọ Efraimu, ati Manasse
ngbe;
4 Utai ọmọ Ammihudi, ọmọ Omri, ọmọ
Imri, ọmọ Bani, ninu awọn ọmọ Faresi
ọmọ Juda.
5 Ati ninu awọn ara Ṣilo, Asaiah akọbi,
ati awọn ọmọ rẹ̀.
6 Ati ninu awọn ọmọ Sera, Jegueli, ati
awọn arakọnrin wọn, ẹdẹgbẹrin o di mẹwa.
7 Ati ninu awọn ọmọ Benjamini; Sallu,
ọmọ Meṣullamu, ọmọ Hodafiah ọmọ Senua.
8 Ati Ibneiah ọmọ Jerohamu, ati Ela
ọmọ Ussi, ọmọ Mikri, ati Meṣullamu ọmọ
Ṣefatiah, ọmọ Regueli, ọmọ Ibniah;
9 Ati awọn arakọnrin wọn, gẹgẹ bi idile
wọn, ẹgbẹrun o din mẹrinlelogoji. Gbogbo
awọn ọkọnrin wọnyi ni olori ninu awọn
baba ni ile baba wọn.
10 Ati ninu awọn alufa; Jedaiah, ati
Jehoiaribu ati Jakini,
11 Ati Asariah ọmọ Hilkiah, ọmọ Me-
ṣullamu, ọmọ Sadoku, ọmọ Meraiotu, ọmọ
Ahitubu olori ile Ọlọrun;
12 Ati Adaiah ọmọ Jerohamu, ọmọ Pa-
ṣuri, ọmọ Malkijah, ati Maasai ọmọ Adi-
eli, ọmọ Jasera, ọmu Meṣullamu, ọmọ Me-
ṣillemiti, ọmọ Immeri;
13 Ati awọn arakọnrin wọn olori ile
baba wọn, ẹgbẹsan o din ogoji; awọn ala-
gbara akọni ọkọnrin fun iṣẹ ìsin ile Ọlọrun.
14 Ati ninu awọn ọmọ Lefi; Ṣemaiah
ọmọ Haṣubu, ọmọ Asrikamu, ọmọ Haṣa-
biah, ninu awọn ọmọ Merari;
15 Ati Bakbakkari, Hereṣi, ati Galali,
ati Mattaniah ọmọ Mika, ọmọ Sikri, ọmọ
Asafu;
16 Ati Obadiah ọmọ Ṣemaiah, ọmọ Ga-
lali, ọmọ Jedutani, ati Berekiah ọmọ Asa,
ọmọ Elkanah, ti ngbe ileto awọn ara Ne-
tofa.
17 Awọn adena si ni Ṣallumu, ati Ak-
kubu, ati Talmoni, ati Ahimani, ati awọn
arakọnrin wọn; Ṣallumu li olori;
18 Titi di isisiyi awọn ti o duro li oju-
ọ̀na ọba niha ilà-õrùn; adena ni nwọn li
ẹgbẹ awọn ọmọ Lefi.
19 Ati Ṣallumu ọmọ Kore, ọmọ Ebi-
asafu, ọmọ Kora, ati awọn arakọnrin rẹ̀,
ti ile baba rẹ̀, awọn ọmọ Kora, ni mbẹ lori
iṣẹ ìsin na, olutọju iloro agọ na; awọn
baba wọn ti mbẹ lori ibudo Oluwa ti nwọn
ima ṣọ atiwọle na.
20 Ati Finehasi ọmọ Eleasari ni olori
lori wọn ni igba atijọ, Oluwa si wà pẹlu
rẹ̀.
21 Sekariah ọmọ Meṣelemiah ni adena
ilẹkun agọ ajọ enia.
22 Gbogbo wọnyi ti a ti yàn lati ṣe
adena loju iloro, jẹ igba o le mejila. A ka
awọn wọnyi nipa idile wọn ni ileto wọn,
awọn ẹniti Dafidi ati Samueli, ariran, ti
yàn nitori otitọ wọn.
23 Bẹli awọn wọnyi ati awọn ọmọ wọn
nṣe abojuto iloro ile Oluwa, eyini ni ile agọ
na fun iṣọ.

Digitized by Google

24 Ni igun mẹrẹrin ni awọn adena mbẹ,
niha ilà-õrùn, ìwọ-õrùn, ariwa ati gusu.
25 Ati awọn arakọnrin wọn ngbe ileto
wọn, lati ma wà pẹlu wọn ni ijọ ekeje lati
ìgba de ìgba.
26 Nitoriti awọn ọmọ Lefi wọnyi jẹ awọn
olori adena mẹrin, nwọn si wà ninu iṣẹ na,
nwọn si wà lori iyàra ati ibi iṣura ile
Ọlọrun.
27 Nwọn a si ma sùn yi ile Ọlọrun ka,
nitori ti nwọn ni itọju na, ati ṣiṣi rẹ̀ li oro-
wurọ jẹ ti wọn.
28 Ati awọn kan ninu wọn ni itọju
ohun-elo ìsin, lati ma kó wọn sinu ile ati
si ode ni iye.
29 Ninu wọn li a yàn lati ma bojuto
ohun-elo, ati gbogbo ohun-elo ibi mimọ́,
ati iyẹfun kikunna, ati ọti-waini, ati ororo,
ati ojia, ati turari.
30 Ati omiran ninu awọn ọmọ awọn
alufa si fi turari ṣe ororo,
31 Ati Mattitiah, ọkan ninu awọn ọmọ
Lefi, ti iṣe akọbi Ṣallumu ọmọ Kora, li o
nṣe alabojuto iṣẹ ohun ti a ndín.
32 Ati ninu awọn arakọnrin wọn ninu
awọn ọmọ Kohati li o nṣe itọju akara-ifihan,
lati mã pese rẹ̀ li ọjọjọ isimi.
33 Wọnyi si li awọn akọrin, olori awọn
baba awọn ọmọ Lefi, nwọn kò ni iṣẹ ninu
iyara wọnni; nitori ti nwọn wà lẹnu iṣẹ
wọn lọsan ati loru.
34 Awọn wọnyi ni olori baba awọn ọmọ
Lefi, ni iran wọn, olori ni nwọn: awọn
wọnyi ni ngbe Jerusalemu.
35 Ati ni Gibeoni ni baba Gibeoni ngbe,
Jegieli, orukọ aya ẹniti ijẹ Maaka.
36 Akọbi ọmọ rẹ̀ si ni Abdoni, ati Suri.
ati Kiṣi, ati Baali, ati Neri, ati Nadabu,
37 Ati Gedori, ati Ahio, ati Sekariah ati
Mikloti.
38 Mikloti si bi Ṣimeamu. Awọn
wọnyi si mba awọn arakọnrin wọn gbe ni
Jerusalemu, kọju si awọn arakọnrin wọn.
39 Neri si bi Kiṣi, Kiṣi si bi Saulu,
Saulu si bi Jonatani, ati Malkiṣua, ati
Abinadabu, ati Eṣbaali.
40 Ati ọmọ Jonatani ni Merib-baali;
Merib-baali si bi Mika.
41 Ati awọn ọmọ Mika ni Pitoni, ati
Meleki, ati Tarea, ati Ahasi.
42 Ahasi si bi Jara ; Jara si bi Alemeti,
ati Asmafeti, ati Simri, Simri bi Mosa,
43 Mosa si bi Binea, ati Refaiah ọmọ rẹ̀,
Eleasa ọmọ rẹ̀, Aseli ọmọ rẹ̀.
44 Aseli si bi ọmọ mẹfa, orukọ wọn ni
wọnyi; Asrikamu, Bokeru, ati Ismaeli,
ati Ṣeariah, ati Obadiah ati Hanani.
Wọnyi li awọn ọmọ Aseli.

## ORI 10.

AWỌN ara Filistia si ba Israeli jagun,
awọn ọkọnrin Israeli si sá niwaju
awọn ara Filistia, nwọn fi ara pa, nwọn si
ṣubu li òke Gilboa.
2 Awọn ara Filistia si lepa Saulu kikan,
ati awọn ọmọ rẹ̀: awọn ara Filistia si pa
Jonatani, ati Abinadabu, ati Melkiṣua,
awọn ọmọ Saulu.
3 Ogun na si le fun Saulu, awọn tafà-
tafà si ba a, on si damu nitori awọn tafàtafà.
4 Nigbana ni Saulu wi fun ẹniti o ru
ihamọra rẹ̀ pe, Fa idà rẹ yọ, ki o si fi gun
mi, ki awọn alaikọla wọnyi ki o má ba wá
fi mi ṣẹsin. Ṣugbọn ẹniti o ru ihamọra rẹ̀
kọ̀, nitori ẹ̀ru ba a gidigidi. Bẽni Saulu
si mu idà, o si ṣubu le e.
5 Nigbati ẹniti o ru ihamọra rẹ̀ si ri pe
Saulu kú, on na pẹlu si ṣubu le idà rẹ̀, o si
kú.
6 Bẽni Saulu kú, ati awọn ọmọ rẹ̀ mẹ-
tẹta, gbogbo ile rẹ̀ si kú ṣọkan.
7 Nigbati gbogbo awọn ọkọnrin Israeli
ti o wà ni pẹtẹlẹ ri pe nwọn sá, ati pe
Saulu ati awọn ọmọ rẹ̀ kú, nwọn fi ilu wọn
silẹ, nwọn si sá : awọn ara Filistia si wá;
nwọn si joko ninu wọn.
8 O si ṣe ni ijọ keji, nigbati awọn ara
Filistia de lati wá bọ́ awọn okú li aṣọ,
nwọn si ri Saulu pẹlu ati awọn ọmọ rẹ̀ pe,
nwọn ṣubu li òke Gilboa.
9 Nwọn si bọ́ ọ li aṣọ, nwọn si gbé ori
rẹ̀ ati ihamọra rẹ̀, nwọn si ranṣẹ si awọn
ara Filistia yika, lati mu ihin lọ irò fun
awọn ere wọn, ati fun awọn enia.
10 Nwọn si fi ihamọra rẹ̀ sinu ile oriṣa
wọn, nwọn si kan agbari rẹ̀ mọ ile Dagoni.
11 Nigbati gbogbo Jabeṣ-gileadi gbọ́
gbogbo eyi ti awọn ara Filistia ti ṣe si
Saulu,
12 Nwọn dide, gbogbo awọn ọkọnrin
ogun, nwọn si gbé okú Saulu lọ, ati okú
awọn ọmọ rẹ̀, nwọn wá si Jabeṣi, nwọn si
sin egungun wọn labẹ igi oaku ni Jabeṣi,
nwọn si gbawẹ ni ijọ meje.
13 Bẽni Saulu kú ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o da si
Oluwa, nitori ọ̀rọ Oluwa, ti on kò kiyesi,
ati pẹlu nitori o lọ bère ọ̀ràn lọwọ ajẹ, lati
ṣe ibere.
14 Kò si bère lọwọ Oluwa ; nitorina li o
ṣe pa a, o si yi ijọba na pada sọdọ Dafidi
ọmọ Jesse.

Digitized by Google

## ORI 11.

NIGBANA ni gbogbo Israeli ko ara wọn
jọ si ọdọ Dafidi ni Hebroni, wipe,
Kiyesi i, egungun rẹ ati ẹran ara rẹ li awa
iṣe.
2 Ati pẹlu li atijọ, ani nigbati Saulu jẹ
ọba, iwọ li o nmu Israeli jade ti o si nmu u
wá ile: Oluwa Ọlọrun rẹ si wi fun ọ pe,
Ki iwọ ki o bọ Israeli, enia mi, ki iwọ ki o
si ṣe ọmọ-alade lori Israeli enia mi.
3 Nitorina ni gbogbo awọn agbagba
Israeli ṣe tọ ọba wá ni Hebroni; Dafidi si
ba wọn da majẹmu ni Hebroni niwaju
Oluwa; nwọn si fi ororo yan Dafidi li ọba
lori Israeli, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa nipa ọwọ
Samueli.
4 Ati Dafidi ati gbogbo Israeli jade lọ si
Jerusalemu, ti iṣe Jebusi; awọn Jebusi ara
ilẹ na ngbe ibẹ̀.
5 Awọn ara ilu Jebusi si wi fun Dafidi
pe, Iwọ kò gbọdọ wọ̀ ihinyi wa. Ṣugbọn
Dafidi kó ilu odi Sioni ti iṣe ilu Dafidi.
6 Dafidi si wipe, Ẹnikẹni ti o ba tetekọ
kọlù awọn ara Jebusi ni yio ṣe olori ati
balogun. Bẹ̃ni Joabu ọmọ Seruiah si
tetekọ gòke lọ, o si jẹ olori.
7 Dafidi si ngbe inu ilu odi, nitorina ni
nwọn fi npè e ni ilu Dafidi.
8 O si kọ́ ilu na yikakiri; ani lati Millo
yikakiri: Joabu si tun iyokù ilu na ṣe.
9 Bẹ̃ni Dafidi nga, o si npọ̀ si i: ni-
nitori ti Oluwa awọn ọmọ-ogun wà pẹlu rẹ̀.
10 Wọnyi si ni olori awọn ọkọnrin akọni
ti Dafidi ni; awọn ti o fi ara wọn mọ ọ
girigiri ni ijọba rẹ̀, pẹlu gbogbo Israeli,
lati fi i jọba, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa fun Israeli.
11 Eyi ni iye awọn ọkọnrin akọni ti
Dafidi ni; Jaṣobeamu ọmọ Hakmoni, olori
ninu awọn ọgbọ̀n balogun: on li o gbé
ọ̀kọ rẹ̀ soke si ọ̃dunrun enia ti o pa lẹrikan.
12 Lẹhin rẹ̀ ni Eleaseri ọmọ Dodo, ara
Ahohi, ẹniti iṣe ọkan ninu awọn akọni
mẹta.
13 On wà pẹlu Dafidi ni Pasdam-
mimu, nigbati awọn ara Filistia ko ara wọn
jọ lati jagun, nibiti ilẹ-bĩri kan wà ti o
kún fun ọkà barli; awọn enia si salọ kuro
niwaju awọn ara Filistia.
14 Nwọn si duro jẹ li ãrin ilẹ-bĩri na,
nwọn si gbà a, nwọn si pa awọn ara
Filistia; Oluwa si fi igbala nla gbà wọn.
15 Awọn mẹta ninu awọn ọgbọ̀n balogun
si sọ̀kalẹ tọ̀ Dafidi lọ sibi apata na, ninu
iho Adullamu; ogun ara Filistia si do li
afonifoji Refaimu.
16 Dafidi si mbẹ ninu ilu odi nigbana,
ẹgbẹ-ogun awọn ara Filistia si mbẹ ni
Betlehemu li akoko na.
17 Dafidi si kòngbẹ, o si wipe, Emi iba
ri ẹni fun mi mu ninu omi kanga Betle-
hemu ti mbẹ leti ẹnu-bodè!
18 Awọn mẹta na si la inu ogun awọn
ara Filistia kọja, nwọn si fa omi jade lati
inu kanga Betlehemu, lati ẹnu-bodè, nwọn
gbé e, nwọn si mu u tọ̀ Dafidi wá: Dafidi
kò si fẹ mu u, ṣugbọn o tú u silẹ fun
Oluwa,
19 O si wipe, Ki Ọlọrun mi má jẹ ki emi
ki o ṣe eyi: ki emi ki o ha mu ẹ̀jẹ awọn
ọkọnrin wọnyi, ti nwọn fi ẹmi wọn wewu?
nipa ẹmi wọn ni nwọn fi mu u wá. Nito-
rina ni on kò ṣe fẹ mu u, nkan wọnyi li
awọn akọni meta wọnyi ṣe.
20 Ati Abiṣai arakọnrin Joabu, on li
olori ninu awọn mẹta: nitoriti o gbé ọ̀kọ
rẹ̀ soke si ọ̃dunrun o pa wọn, o si ni orukọ
ninu awọn mẹta.
21 O ni ọla jù awọn mẹta ẹgbẹ ekeji lọ
o si jẹ olori wọn: ṣugbọn kò to awọn mẹta
iṣaju.
22 Benaiah, ọmọ Jehoiada, ọmọ akọni
ọkọnrin kan ti Kabseeli, eniti o pọ̀ ni iṣe
agbara, o pa awọn ọmọ Arieli meji ti Moabu;
on sọkalẹ, o si pa kiniun kan ninu iho lako-
ko sno.
23 O si pa ara Egipti kan, ọkọnrin ti o
si sigbọnlẹ, igbọnwọ marun ni gigun rẹ̀; ati
li ọwọ ara Egipti na ni ọ̀kọ kan wà bi idu-
bu igi awunṣọ; o si sọ̀kalẹ tọ ọ lọ pẹlu
ọpa, o si já ọ̀kọ li ọwọ ara Egipti na, o si fi
ọ̀kọ rẹ̀ pa a.
*24 Nkan wọnyi ni Benaiah ọmọ Jehoiada
ṣe, o si li orukọ ninu awọn akọni mẹta.
25 Kiyesi i, o li ọla jù awọn ọ̀gbọn lọ,
ṣugbọn kò to awọn mẹta iṣaju, Dafidi si fi
ṣe olori awọn igbimọ ile rẹ̀.
26 Awọn akọni ọkọnrin ọmọ-ogun rẹ̀ ni
Asaheli arakọnrin Joabu, Elhanani, ọmọ
Dodo, ara Betlehemu.
27 Sammotu, ara Harori, Helesi, ara
Peloni,
28 Ira, ọmọ Ikkeṣi, ara Tekoa, Abieseri
ara Anatoti,
29 Sibbekai, ara Husa, Ilai, ara Ahohi,
30 Maharai, ara Netofa, Heledi ọmọ
Baana, ara Netofa.
31 Itai ọmọ Ribai ti Gibea, ti awọn ọmọ
Benjamini, Benaiah ara Piratoni,
32 Hurai ti odò Gaaṣi, Abieli ara Arbati,
33 Asmafeti ara Baharumi, Eliaba ara
Ṣaalboni.

Digitized by Google

34 Awọn ọmọ Haṣemu ara Gisoni, Jonatani ọmọ Sage, ara Harari.
35 Ahihamu ọmọ Sakari, ara Harari, Elifali ọmọ Uri,
36 Heferi ara Mekerati, Ahijah ara Peloni,
37 Hesro ara Karmẹli,Naari ọmọ Esbai,
38 Joeli arakọnrin Natani, Mibhari ọmọ Haggeri,
39 Saleki ara Ammoni, Naharai ara Beroti, ẹniti nru ihamọra Joabu ọmọ Seruiah,
40 Ira ara Itri, Garobu ara Itri,
41 Uriah ara Heti, Sabadi ọmọ Ahalai,
42 Adina ọmọ Ṣisa ara Reubeni, olori awọn ara Reubeni, ati ọgbọ̀n enia pẹlu rẹ̀.
43 Hanani ọmọ Maaka, ati Jehoṣafati ara Mitini,
44 Ussia ara Aslerati, Ṣama ati Jegieli, awọn ọmọ Hotani, ara Aroeri,
45 Jediaeli ọmọ Simri,ati Joha arakọnrin rẹ̀ ara Tisi,
46 Elieli ara Mahafi ati Jeribai, ati Joṣafia, awọn ọmọ Elnaamu, ati Tima ara Moabu.
47 Elieli, ati Obedi, ati Jasieli ara Mesobah.

## ORI 12.

WỌNYI si li awọn ti o tọ̀ Dafidi wá si
Siklagi, nigbati o fi ara rẹ̀ pamọ,
nitori Saulu ọmọ Kiṣi: awọn wọnyi si wà
ninu awọn akọni ti nṣe oluranlọwọ ogun
na.
2 Nwọn le tafa, nwọn si le fi ọwọ ọtún
ati ọwọ òsi sọ okuta, ati fi ọrun tafa, ani
ninu awon arakọnrin Saulu ti Benjamini.
3 Ahieseri ni olori, ati Joaṣi, awọn ọmọ
Ṣemaa ara Gibea; ati Jẹsieli ati Peleti,
awọn ọmọ Asmafeti; ati Beraka, ati Jehu
ara Anatoti,
4 Ati Ismaiah ara Gibeoni, akọni ninu
awọn ọgbọ̀n, ati lori ọgbòn (enia) ati Jeremiah, ati Jahasieli, ati Johanani, ati Josabadi ara Gedera.
5 Elusai ati Jeremoti, ati Bealiah, ati
Ṣemariah, ati Ṣefatiah ara Harofi,
6 Elkana, ati Jesiah, ati Asareelti ati
Joeseri, ati Jaṣobeamu, awọn ara Kora,
7 Ati Joeli, ati Sebadiah, awọn ọmọ
Jerohamu ti Gedori.
8 Ati ninu awọn ara Gadi, awọn ọkọnrin akọni kan ya ara wọn sọdọ Dafidi ninu
iho ni iju, awọn ọkọnrin ogun ti o yẹ fun
ija ti o le di asà on ọ̀kọ mu, oju awọn ẹniti
o dabi oju kiniun, nwọn si yara bi agbọnrin
lori awọn òke nla;
9 Eseri ekini, Obadiah ekeji, Eliobu
ẹkẹta,
10 Miṣmanna ẹkẹrin, Jeremiah ẹkarun,
11 Attai ẹkẹfa, Elieli ekje,
12 Johanani ẹkẹjọ, Elsabadi ẹkẹsan,
13 Jeremiah ẹkẹwa, Makbanai ẹkọkanla.
14 Awọn wọnyi li awọn ọmọ Gadi, awọn
olori ogun: ẹniti o kere jù to fun ọgọrun
enia, ati ẹniti o pọ̀ju to fun ẹgbẹrun.
15 Wọnyi li awọn ti o gòke odò Jordani
li oṣù ekini, nigbati o kún bò gbogbo bèbe
rẹ̀; nwọn si le gbogbo awọn ti o wà li
afonifoji ninu ila-õrùn, ati niha iwọ-õrùn.
16 Ninu awọn ọmọ Benjamini ati Juda
si tọ Dafidi wá lori òke.
17 Dafidi si jade lọ ipade wọn, o si dahun
o si wi fun wọn pe, Bi o ba ṣepe ẹnyin tọ̀ mi
wá li alafia lati ràn mi lọwọ, ọkàn mi yio
-ṣọkan pẹlu nyin: ṣugbọn bi o ba ṣepe
ẹnyin wá lati fi mi hàn fun awọn ọta mi,
nigbati ẹbi kò si lọwọ mi, ki Ọlọrun awọn
baba wa ki o wò o, ki o si ṣe idajọ.
18 Nigbana ni ẹmi bà lé Amasai, ti iṣe
olori awọn ọgbọn na, wipe, Tirẹ li awa,
Dafidi, tirẹ li a si nṣe, iwọ ọmọ Jesse:
alafia! alafia ni fun ọ! alafia si ni fun
awọn oluranlọwọ rẹ; nitori Ọlọrun rẹ ni
nràn ọ lowọ. Dafidi si gbà wọn, o si fi
wọn jẹ olori ẹgbẹ-ogun.
19 Ninu ẹyà Manasse si ya si ọdọ Dafidi,
nigbati o ba awọn ara Filistia wá lati ba
Saulu jagun, ṣugbọn nwọn kò ràn wọn
lọwọ: nitori awọn olori awọn ara Filistia,
nigbati nwọn gbero, rán a lọ wipe, Ti on ti
ori wa ni on o fi pada lọ si ọdọ Saulu
oluwa rẹ̀.
20 Bi on ti lọ si Siklagi, ninu awọn ẹya
Manasse ya si ọdọ rẹ̀, Adna, ati Josabadi,
Jediaeli, ati Mikaeli, ati Josabadi ati Elihu,
ati Sittai, awọn olori ẹgbẹgbẹrun ti iṣe ti
Manasse.
21 Nwọn si ràn Dafidi lọwọ si ẹgbẹ
ogun na; nitori gbogbo wọn ni akọni enia,
nwọn si jẹ olori ninu awọn ọmọ-ogun.
22 Nitori li akokò na li ojojumọ ni
nwọn ntọ Dafidi wá lati ran a lọwọ, titi o
fi di ogun nla, gẹgẹ bi ogun Ọlọrun.
23 Eyi ni iye awọn enia na ti o hamọra
tan fun ogun, ti nwọn si tọ̀ Dafidi wá si
Hebroni, lati pa ijọba Saulu dà si ọdọ rẹ̀
gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa.
24 Awọn ọmọ Juda ti ngbe asa ati ọ̀kọ,
jẹ ẹgbãta enia o le ẹgbẹrin, ti o hamọra
tan fun ogun.

Digitized by Google

25 Ninu awọn ọmọ Simeoni, akọni enia
fun ogun ọ̃dẹgbãrin o le ọgọrun.
26 Ninu awọn ọmọ Lefi, ẹgbãji o le
ẹgbẹta.
27 Jehoiada olori fun Aaroni, ẹgbẽdogun
enia o le ọ̃dẹgbẹrin si wà pẹlu rẹ̀.
28 Ati Sadoku, akọni ọdọmọkọnrin, ati
ninu ile baba rẹ̀ olori mejilelogun.
29 Ati ninu awọn ọmọ Benjamini, awọn
arakọnrin Saulu ẹgbẽdogun: nitori titi di
isisiyi, ọ̀pọlọpọ ninu wọn li o ti ntọju iṣọ
ile Saulu.
30 Ati ninu awọn ọmọ Efraimu ẹgbãwa
o le ẹgbẹrin, akọni ọkọnrin, enia olorukọ
ni nwọn ni ile baba wọn.
31 Ati àbọ ẹ̀ya Manasse ẹgbãsan, ti a
yan nipa orukọ, lati lọ fi Dafidi jẹ ọba.
32 Ati ninu awọn ọmọ Issakari, ti o ni
oye akoko, lati mọ̀ ohun ti Israeli iba ma
ṣe; olori wọn jẹ igba; ati gbogbo awọn
arakọnrin wọn mbẹ ni ikawọ wọn.
33 Ninu ti Sebuluni, iru awọn ti o jade
lọ si ogun ti o mọ̀ ogun iwé, pẹlu gbogbo
ohun èlo ogun, ẹgbamẽdọgbọn; ti nwọn kì
ifi iye-meji tẹgun.
34 Ati ninu ti Naftali ẹgbẹrun olori
ogun, ati pẹlu wọn ti awọn ti asa ati ọ̀kọ
ẹgbã mejidilogun o le ẹgbẹrun.
35 Ati ninu awọn ọmọ Dani ti o mọ̀
ogun iwé, ẹgbã mẹtala o le ẹgbẹta.
36 Ati ninu ti Aṣeri, iru awọn ti njade
lọ si ogun, ti o mọ̀ ogun iwé, ọkẹ meje.
37 Ati li apa keji odò Jordani, ninu ti
awọn ọmọ Reubeni, ati awọn ọmọ Gadi,
ati abọ ẹya Manasse, pẹlu gbogbo onirũru
ohun-elo ogun fun ogun, ọkẹ mẹfa.
38 Gbogbo awọn ọkọnrin ogun wọnyi ti
nwọn mọ̀ bi a iti itẹ ogun, nwọn fi ọkàn
pipe wá si Hebroni, lati fi Dafidi jọba lori
Israeli: gbogbo awọn iyokù ninu Israeli si
jẹ oninu kan pẹlu lati fi Dafidi jẹ ọba.
39 Nibẹ ni nwọn si wà pẹlu Dafidi ni ijọ
mẹta, nwọn njẹ, nwọn si nmu, nitoriti
awọn ará wọn ti pèse fun wọn.
40 Pẹlupẹlu awọn ti o sunmọ wọn, ani
titi de ọdọ Issakari, ati Sebuluni, ati Nafta-
li, mu akara wá lori kẹtẹkẹtẹ, ati lori ibaka-
siẹ, ati lori ibãka, ati lori malu, ani onjẹ ti
iyẹfun, eso ọ̀pọtọ, ati eso àjara gbigbẹ, ati
ọti-waini, ati ororo, ati malu, ati agutan li
ọ̀pọlọpọ: nitori ti ayọ̀ wà ni Israeli.

## ORI 13.

DAFIDI si ba awọn olori ogun ẹgbẹgbẹ-
run ati ọrọrun ati olukuluku olori
gbèro.
2 Dafidi si wi fun gbogbo ijọ Israeli pe,
Bi o ba dara loju nyin, bi o ba si ti ọwọ
Oluwa Ọlọrun wa wá, jẹ ki a ranṣẹ kiri sọ-
dọ awọn arakọnrin wa ni ibi gbogbo, ti o
kù ni gbogbo ilẹ Israeli, ati pẹlu wọn si
alufa ati awọn ọmọ Lefi ti mbẹ ni ilu agbe-
gbe wọn, ki nwọn ki o le ko ara wọn jọ
sọdọ wa:
3 Ẹ jẹ ki a si tun mu apoti-ẹri Ọlọrun
wa wa si ọdọ wa: nitoriti awa kò ṣafẹri rẹ̀
li ọjọ Saulu.
4 Gbogbo ijọ na si wipe, ẹ jẹ ki a ṣe bẹ̃:
nitori ti nkan na tọ loju gbogbo enia.
5 Bẹ̃ni Dafidi ko gbogbo Israeli jọ lati
odò Egipti ani titi de Hemati, lati mu
apoti-ẹri Ọlọrun lati Kirjat-jearimu wá.
6 Dafidi si gòke ati gbogbo Israeli si
Baala, si Kirjat-jearimu, ti iṣe ti Juda,
lati mu apoti-ẹri Ọlọrun Oluwa gòke lati
ibẹ wá, ti ngbe arin Kerubimu, nibiti a npe
orukọ Ọlọrun.
7 Nwọn si gbé apoti-ẹri Ọlọrun ka kẹkẹ́
titun lati inu ile Abinadabu wá, ati Ussa
ati Ahio ntọ́ kẹkẹ́ na.
8 Ati Dafidi ati gbogbo Israeli fi gbogbo
agbara wọn ṣire niwaju Ọlọrun, pẹlu orin,
ati pẹlu duru, ati pẹlu psalteri, ati pẹlu
timbreli, ati pẹlu simbali, ati pẹlu ipè.
9 Nigbati nwọn si de ilẹ ipaka Kidroni,
Ussa nà ọwọ rẹ̀ lati di apoti-ẹri na mu;
nitoriti awọn malu kọsẹ.
10 Ibinu Oluwa si ru si Ussa, o si lù u,
nibẹ li o si kú niwaju Ọlọrun.
11 Dafidi si binu nitori ti Oluwa ké
Ussa kuro: nitorina ni a ṣe pè ibẹ na ni
Peres-Ussa titi di oni.
12 Dafidi si bẹru Ọlọrun li ọjọ na wipe,
Emi o ha ṣe mu apoti-ẹri Ọlorun wá sọdọ
mi?
13 Bẹ̃ni Dafidi kò mu apoti-ẹri na bọ̀ si
ọdọ ara rẹ̀ si ilu Dafidi, ṣugbọn o gbé e ya
si ile Obed-Edomu ara Gitti.
14 Apoti-ẹri Ọlọrun si ba awọn ara ile
Obed-Edomu gbe ni ile rẹ̀ li oṣu mẹta.
Oluwa si bukún ile Obed-Edomu ati ohun
gbogbo ti o ni.

## ORI 14.

HIRAMU ọba Tire si ran onṣẹ si Dafidi,
ati igi Kedari, pẹlu awọn ọmọle ati
gbẹnagbẹna, lati kọ́le fun u.
2 Dafidi si woye pe, Oluwa ti fi idi on
joko li ọba lori Israeli, nitori a gbé ijọba rẹ̀
ga nitori ti awọn enia rẹ̀, Israeli.
3 Dafidi si mu awọn aya si i ni Jerusa-

Digitized by Google

lemu: Dafidi si bi ọmọkọnrin ati ọmọbirin
si i.
4 Wọnyi si li orukọ awọn ọmọ rẹ̀ ti o ni
ni Jerusalemu; Ṣammua ati Ṣobabu Nata-
ni, ati Solomoni,
5 Ati Ibhari, ati Eliṣua, ati Elpaleti,
6 Ati Noga, ati Nefegi, ati Jafia,
7 Ati Eliṣama, ati Beeliada, ati Elifa-
leti.
8 Nigbati awọn ara Filistia si gbọ́ pe, a
fi ororo yan Dafidi li ọba lori gbogbo Isra-
eli, gbogbo awọn ara Filistia gòke lọ iwá
Dafidi: Dafidi si gbọ́, o si jade tọ̀ wọn.
9 Awọn ara Filistia si wá, nwọn si tẹ
ara wọn ni afonifoji Refaimu.
10 Dafidi si bere lọdọ Ọlọrun wipe, Ki
emi ki o gòke tọ awọn ara Filistia lọ?
Iwọ o ha fi wọn le mi lọwọ? Oluwa si wi
fun u pe, Gòke lọ, emi o si fi wọn le ọ lọwọ.
11 Bẹ̃ni nwọn gòke lọ si Baal-perasimu;
Dafidi si kọlù wọn nibẹ. Dafidi wi wipe,
Ọlọrun ti ti ọwọ mi yà lu awọn ọta mi bi
yiya omi: nitorina ni nwọn ṣe npè ibẹ na
ni Baal-perasimu.
12 Nwọn si fi awọn orisa wọn silẹ nibẹ,
Dafidi si wipe, ki a fi iná sun wọn.
13 Awọn ara Filistia si tun tẹ ara wọn
kakiri ni afonifoji.
14 Nitorina ni Dafidi tun bère lọwọ
Ọlọrun: Ọlọrun si wi fun u pe, Máṣe gòke
tọ̀ wọn; yipada kuro lọdọ wọn, ki o si ja
lu wọn niwaju igi mulberi.
15 Yio si ṣe, nigbati iwọ ba gbọ́ iro ẹsẹ
lòke igi mulberi, nigbana ni ki iwọ ki o
gbogun jade: nitori Ọlọrun jade ṣaju rẹ lọ
lati kọlù ogun awọn ara Filistia.
16 Dafidi si ṣe gẹgẹ bi Ọlọrun ti paṣẹ fun
u: nwọn si kọlù ogun awọn ara Filistia
lati Gibeoni titi de Gaseri.
17 Okiki Dafidi si kan yi gbogbo ilẹ ka?
Oluwa si mu ki ẹ̀ru rẹ ki o ba gbogbo orilẹ-
ède.

## ORI 15.

DAFIDI si kọ́ ile fun ara rẹ̀ ni ilu Dafidi,
o si pese ipò kan fun apoti-ẹri Ọlọrun,
o si pa agọ kan fun u.
2 Nigbana ni Dafidi wipe, Ẹnikan kò yẹ
lati rù apoti-ẹri Ọlọrun bikoṣe awọn ọmọ
Lefi; nitori awọn ni Oluwa ti yàn lati ma
gbé apoti-ẹri Ọlọrun, ati lati ma ṣe iranṣẹ
fun u titi lai.
3 Dafidi si ko gbogbo Israeli jọ si Jeru-
salemu, lati gbé apoti-ẹri Oluwa gòke lọ si
ipò rẹ̀ ti o ti pese fun u.
4 Dafidi si pè awọn ọmọ Aaroni, ati
awọn ọmọ Lefi jọ.
5 Ninu awọn ọmọ Kohati; Urieli olori,
ati awọn arakọnrin rẹ̀ ọgọfa:
6 Ninu awọn ọmọ Merari; Asaiah olori,
ati awọn arakọnrin rẹ̀ igba o le ogun:
7 Ninu awọn ọmọ Gerṣọmu; Joeli olori,
ati awọn arakọnrin rẹ̀ ãdoje:
8 Ninu awọn ọmọ Elisafani; Ṣemaiah
olori, ati awọn arakọnrin rẹ̀ igba.
9 Ninu awọn ọmọ Hebroni; Elieli olori,
ati awọn arakọnrin rẹ̀ ọgọrin;
10 Ninu awọn ọmọ Ussieli; Aminadabu
olori, ati awọn arakọnrin rẹ̀ mejilelãdọfa.
11 Dafidi si ranṣẹ pè Sadoku ati Abiata-
ri awọn alufa; ati awọn ọmọ Lefi, Urieli,
Asaiah, ati Joeli, Ṣemaiah, ati Elieli, ati
Aminadabu;
12 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin li olori
awọn baba awọn ọmọ Lefi: ẹ ya ara nyin
si mimọ́, ẹnyin ati awọn arakọnrin nyin,
ki ẹnyin ki o le gbé apoti-ẹri Oluwa Ọlọrun
Israeli gòke lọ si ibi ti mo ti pèse fun u.
13 Nitoriti ẹnyin kò rù u li akọṣe, ni
Oluwa Ọlọrun wa fi ṣe ẹ̀ya si wa li ara, ni-
tori awa kò wá a bi o ti yẹ.
14 Bẹ̃ li awọn alufa ati awọn ọmọ Lefi
ya ara wọn si mimọ́ lati gbe apoti-ẹri Olu-
wa Ọlọrun Israeli gòke wá.
15 Awọn ọmọ Lefi si rù apoti-ẹri Ọlọrun
bi Mose ti pa a li aṣẹ gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa,
nwọn fi ọpa rù u li ejika wọn.
16 Dafidi si wi fun olori awọn ọmọ Lefi
pe ki nwọn yàn awọn arakọnrin wọn, awọn
akọrin pẹlu ohun-èlo orin, psalteri ati du-
ru, ati kimbali; ti ndún kikan ti o si nfi
ayọ gbé ohùn soke.
17 Bẹ̃ li awọn ọmọ Lefi yan Hemani
ọmọ Joeli: ati ninu awọn arakọnrin rẹ̀,
Asafu ọmọ Berekiah; ati ninu awọn ọmọ
Merari arakọnrin wọn, Etani ọmọ Kuṣaiah;
18 Ati pẹlu wọn awọn arakọnrin wọn li
ọwọ́ keji; Sekariah, Beni, ati Jaasieli, ati
Ṣemiramotu, ati Jehieli, ati Unni, Eliabu,
ati Benaiah, ati Maaseiah, ati Obed-Edo-
mu, ati Jeieli awọn adena.
19 Awọn akọrin si ni Hemani, Asafu,
ati Etani, ti awọn ti kimbali ti ndun
kikan;
20 Ati Sekariah, ati Asieli, ati Ṣemira-
motu, ati Jelieli, ati Unni, ati Eliabu, ati
Maaseiah, ati Benaiah, ti awọn ti psaltiri
olohùn òke;
21 Ati Mattitiah, ati Elifeleti, ati Mi-
kneiah, lati fi duru olokun mẹjọ ṣaju orin.
22 Ati Kenaniah, olori awọn ọmọ Lefi

Digitized by Google

ni ọga orin: on ni nkọni li orin, nitoriti o
moye rẹ̀.
23 Ati Berekiah, ati Elkana li awọn
adena fun apoti-ẹri na.
24 Ati Ṣebaniah, ati Jehoṣafati, ati Netaneeli, ati Amasai, ati Sekariah, ati Benaiah, ati Elieseri, awọn alufa, li o nfun ipè
niwaju apoti ẹri Ọlọrun: ati Obed Edomu,
ati Jehiah li awọn adena fun apoti-ẹri na.
25 Bẹ̃ni Dafidi ati awọn agbagba Israeli,
ati awọn olori ẹgbẹgbẹrun, lọ lati igbé
apoti-ẹri majẹmu Oluwa jade ti ile Obed-Edomu gòke wá pẹlu ayọ̀.
26 O si ṣe, nigbati Ọlọrun ràn awọn ọmọ
Lefi lọwọ ti o rù apoti-ẹri majẹmu Oluwa,
ni nwọn fi malu meje ati àgbo meje rubọ.
27 Dafidi si wọ̀ aṣọ igunwa ọ̀gbọ daradara, ati gbogbo awọn ọmọ Lefi ti nrù
apoti-ẹri na, ati awọn akọrin, ati Keniah
olori orin pẹlu awọn akọrin: efodu ọ̀gbọ
si wà lara Dafidi.
28 Bayi ni gbogbo Israeli gbé apoti-ẹri
majẹmu Oluwa gòke wá pẹlu iho ayọ̀, ati
iró fère, ati pẹlu ipè, ati kimbali, psalteri
ati duru si ndún kikankikan.
29 O si ṣe bi apoti-ẹri majẹmu Oluwa
na ti de ilu Dafidi ni Mikali ọmọ Saulu
obirin yọju wode ni fèrese, o ri Dafidi ọba
njo, o si nṣire; o si kẹgan rẹ̀ li ọkàn rẹ̀.

## ORI 16.

BẸ̃NI nwọn mu apoti-ẹri Ọlọrun wá,
nwọn si fi 'si arin agọ na ti Dafidi pa
fun u: nwọn si ru ẹbọ sisun ati ẹbọ alafia
niwaju Ọlọrun,
2 Nigbati Dafidi si ti pari riru ẹbọ sisun
ati ẹbọ alafia tan, o sure fun awọn enia li
orukọ Oluwa.
3 O si fi fun gbogbo enia Israeli, ati
ọkọnrin ati obirin fun olukulùku iṣu akara
kan, ati ekiri ẹran kan, ati akara didùn kan.
4 O si yan ninu awọn ọmọ Lefi lati ma
jọsin niwaju apoti-ẹri Oluwa, ati lati ṣe
iranti, ati lati dupẹ, ati lati yìn Oluwa
Ọlọrun Israeli:
5 Asafu ni olori, ati atẹle rẹ̀ ni Sekariah,
Jeieli, ati Ṣemiramotu, ati Jehieli, ati
Mattitiah, ati Eliabu, ati Benaiah, ati
Obed-Edomu: ati Jeieli pẹlu psalteri ati
pẹlu duru; ṣugbọn Asafu li o nlù kimbali
kikan;
6 Benaiah pẹlu ati Jahasieli awọn alufa
pẹlu ipè nigbagbogbo niwaju apoti-ẹri ti
majẹmu Ọlọrun.
7 Li ọjọ na ni Dafidi kọ́ fi orin mimọ́
yi le Asafu lọwọ lati dupẹ lọwọ Oluwa.
8 Ẹ fi ọpẹ fun Oluwa, ẹ pè orukọ rẹ̀,
ẹ fi iṣẹ rẹ̀ hàn ninu awọn enia.
9 Ẹ kọrin si i, ẹ kọ́ orin mimọ́ si i, ẹ
ma sọ̀rọ gbogbo iṣẹ iyanu rẹ̀.
10 Ẹ ma ṣogo li orukọ rẹ̀ mimọ́; jẹ ki
ọkàn awọn ti nwá Oluwa ki o yọ̀.
11 Ẹ ma wá Oluwa, ati ipá rẹ̀, ma wá
oju rẹ̀ nigbagbogbo.
12 Ẹ ma ranti iṣẹ iyanu rẹ̀ ti o ti ṣe,
iṣẹ àmi rẹ̀, ati idajọ ẹnu rẹ̀;
13 Ẹnyin iru-ọmọ Israeli iranṣẹ rẹ̀, ẹnyin
ọmọ Jakobu ayanfẹ rẹ̀.
14 On ni Oluwa Ọlọrun wa, idajọ rẹ̀
mbẹ ni gbogbo aiye.
15 Ẹ ma ṣe iranti majẹmu rẹ̀ titi lai,
ọ̀rọ ti o ti pa li aṣẹ fun ẹgbẹrun iran;
16 Majẹmu ti o ba Abrahamu da, ati
ibura rẹ̀ fun Isaaki;
17 A si tẹnumọ eyi li ofin fun Jakobu,
ati fun Israeli ni majẹmu aiyeraiye:
18 Wipe, Iwọ li emi o fi ilẹ Kenaani
fun, ipin ilẹ-ini nyin.
19 Nigbati ẹnyin wà ni kiun ni iye, ani
diẹ kiun, ati atipo ninu rẹ̀.
20 Nwọn si nlọ lati orilẹ-ède de orilẹ-ède, ati lati ijọba kan de ọdọ enia miran;
21 On kò jẹ ki ẹnikẹni ki o ṣe wọn ni
ìwọsi, nitõtọ, o ba awọn ọba wi nitori wọn.
22 Wipe, Ẹ má ṣe fi ọwọ kan ẹni-ororo
mi, ẹ má si ṣe awọn woli mi ni ibi.
23 Ẹ kọrin titun si Oluwa gbogbo aiye;
ẹ ma fi igbala rẹ̀ hàn lati ọjọ de ọjọ.
24 Ẹ sọ̀rọ ogo rẹ̀ ninu awọn keferi; ati
iṣẹ-iyanu rẹ̀ ninu gbogbo enia.
25 Nitori titobi li Oluwa, o si ni iyìn
gidigidi: on li o si ni ibẹ̀ru jù gbogbo
oriṣa lọ.
26 Nitori pe gbogbo oriṣa awọn enia,
ere ni nwọ́n: ṣugbọn Oluwa li o da awọn
ọrun.
27 Ogo on ọlá wà niwaju rẹ̀; agbara ati
ayọ̀ mbẹ ni ipò rẹ̀.
28 Ẹ fi fun Oluwa, ẹnyin ibatan enia,
ẹ fi ogo ati ipa fun Oluwa.
29 Ẹ fi ogo fun Oluwa ti o yẹ fun orukọ
rẹ̀: mu ọrẹ wá, ki ẹ si wá siwaju rẹ̀; ẹ
sin Oluwa ninu ẹwà ìwa-mimọ́.
30 Ẹ warìri niwaju rẹ̀, gbogbo aiye:
aiye pẹlu si fi idi mulẹ ti kì o fi le yi.
31 Jẹ ki awọn ọrun ki o yọ̀, si jẹ ki inu
aiye ki o dùn; si jẹ ki a wi ninu awọn
orilẹ-ède pe, Oluwa jọba.
32 Jẹ ki okun ki o ma ho, ati ẹkún rẹ̀:
jẹ ki papa-oko tùtu ki o yọ̀, ati ohun
gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀.
33 Nigbana ni awọn igi igbo yio ma



Digitized by Google

ho niwaju Oluwa, nitori ti o mbọ wá ṣe
idajọ aiye.
34 Ẹ fi ọpẹ fun Oluwa, nitori ti o ṣeun:
nitoriti ãnu rẹ̀ duro lailai.
35 Ki ẹ si wipe, Gbà wa Ọlọrun igbala
wa, si gbá wa jọ, ki o si gbà wa lọwọ awọn
keferi, ki awa ki o le ma fi ọpẹ fun orukọ
rẹ mimọ́, ki a si le ma ṣogo ninu iyìn rẹ.
36 Olubukún li Oluwa Ọlọrun Israeli lai
ati lailai. Gbogbo awọn enia si wipe,
Amin, nwọn si yìn Oluwa.
37 Bẹ̃ li o fi Asafu ati awọn arakọnrin
rẹ̀ silẹ nibẹ niwaju apoti-ẹri majẹmu Oluwa
lati ma jọsìn niwaju apoti-ẹri na nigba-
gbogbo, bi iṣẹ ojojumọ ti nfẹ.
38 Ati Obed-Edomu pẹlu awọn ara-
kọnrin wọn, enia mejidilãdọrin; ati Obed-
Edomu ọmọ Jedutuni, ati Hosa lati ma ṣe
adena:
39 Sadoku alufa, ati awọn arakọnrin rẹ̀,
awọn alufa, niwaju agọ Oluwa, ni ibi giga
ti o wà ni Gibeoni,
40 Lati ma ru ẹbọ sisun si Oluwa lori
pẹpẹ ẹbọ sisun nigbagbogbo li owurọ ati
li alẹ, gẹgẹ bi gbogbo eyi ti a kọ ninu ofin
Oluwa, ti o pa li aṣẹ fun Israeli;
41 Ati pẹlu wọn Hemani ati Jedutuni,
ati awọn iyokù ti a yàn, ti a si pè li orukọ,
lati ma fi ìyin fun Oluwa, nitori ti ãnu
rẹ̀ duro lailai;
42 Ati pẹlu wọn Hemani ati Jedutuni
pẹlu ipè ati kimbali fun awọn ti yio ma
pariwo, ati pẹlu ohun-èlo orin Ọlọrun.
Awọn ọmọ Jedutuni li awọn adena.
43 Gbogbo awọn enia si lọ olukuluku
si ile rẹ̀: Dafidi si yipada lati sure fun
ile rẹ̀.

## ORI 17.

O SI ṣe, bi Dafidi ti joko ninu ile rẹ̀,
ni Dafidi sọ fun Natani woli pe, Wò
o, emi ngbe inu ile kedari, ṣugbọn apoti-
ẹri majẹmu Oluwa ngbe abẹ aṣọ-tita.
2 Nigbana ni Natani wi fun Dafidi pe,
Ṣe ohun gbogbo ti mbẹ ni inu rẹ; nitoriti
Ọlọrun wà pẹlu rẹ.
3 O si ṣe li oru kanna ni ọ̀rọ Ọlọrun tọ
Natani wá, wipe,
4 Lọ, si sọ fun Dafidi iranṣẹ mi pe, Bayi
li Oluwa wi, Iwọ kò gbọdọ kọ́ ile fun mi
lati ma gbe.
5 Nitori emi kò ti igbe inu ile lati ọjọ
ti mo ti mu Israeli gòke wá titi fi di oni
yi; ṣugbọn emi nlọ lati agọ de agọ, ati lati
ibugbe kan de keji.
6 Nibikibi ti mo ti nrin larin gbogbo
Israeli, emi ha sọ̀rọ kan fun ọkan ninu
awọn onidajọ Israeli, ti emi ti paṣẹ fun
lati ma bọ awọn enia mi, emi ha ti wipe,
Ẽṣe ti ẹnyin kò fi kọ́ ile igi kedari fun
mi bi?
7 Njẹ nitorina bayi ni iwọ o wi fun
Dafidi iranṣẹ mi, Bayi li Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi, Emi mu ọ kuro ni pápá
oko-tutu, ani kuro lati ma tọ agutan
lẹhin, ki iwọ ki o le ma ṣe olori awọn
enia mi Israeli.
8 Emi si ti wà pẹlu rẹ ni ibikibi ti iwọ
ba lọ, emi si ti ké gbogbo awọn ọta rẹ
kuro niwaju rẹ, emi o si ṣe ọ li olorukọ
kan, bi orukọ awọn enia nla ti o ti wà li
aiye.
9 Emi o si yàn ibi kan fun Israeli awọn
enia mi, emi o si gbìn wọn, ki nwọn le
má gbe ipò wọn, a kì yio si ṣì wọn mọ;
bẹ̃ni ọmọ buburu kì yio yọ wọn lẹnu mọ,
bi ti atijọ;
10 Ati bi igba ti emi ti fi enia jẹ onidajọ
lori awọn enia mi Israeli. Ati pẹlu emi
o ṣẹgun gbogbo awọn ọta rẹ. Pẹlupẹlu
mo ti sọ fun ọ pe, Oluwa yio kọle kan
fun ọ.
11 Yio si ṣe, nigbati ọjọ rẹ ba pe, ti
iwọ o lọ pẹlu awọn baba rẹ, ni emi o
gbé iru-ọmọ rẹ dide lẹhin rẹ, ti yio jẹ
ọkan ninu awọn ọmọ rẹ ọkọnrin; emi o
si fi idi ijọba rẹ̀ mulẹ.
12 On o kọ́ ile fun mi, emi o si fi idi
itẹ rẹ̀ mulẹ lailai.
13 Emi o jẹ baba fun u, on o si jẹ ọmọ
fun mi; emi kì yio si gbà ãnu mi kuro
lọdọ rẹ̀, bi mo ti gbà a lọwọ ẹniti o ti wà
ṣaju rẹ:
14 Ṣugbọn emi o fi idi rẹ̀ kalẹ ninu ile
mi ati ninu ijọba mi lailai, a o si fi idi
itẹ rẹ̀ mulẹ lailai.
15 Gẹgẹ bi gbogbo ọ̀rọ wọnyi, ati gẹgẹ
bi gbogbo iran yi, bẹ̃ni Natani sọ fun
Dafidi.
16 Dafidi ọba si wá, o si joko niwaju
Oluwa, o si wipe, Tali emi Oluwa Ọlọrun,
ati kini ile mi, ti iwọ si mu mi de ihinyi?
17 Ohun kekere si li eyi li oju rẹ, Ọlọ-
run: iwọ si ti ṣọ pẹlu sipa ile iranṣẹ rẹ fun
akokò jijin ti mbọ̀, o si ka mi si bi iṣe enia
giga, Oluwa Ọlọrun.
18 Kini Dafidi le tun ma sọ pẹlu fun ọ
niti ọlá ti a bù fun iranṣẹ rẹ? iwọ sa mọ̀
iranṣẹ rẹ.
19 Oluwa, nitoriti iranṣẹ rẹ, ati gẹgẹ bi
ti inu rẹ, ni iwọ ti ṣe gbogbo ohun nlanla
yi, ni sisọ gbogbo nkan nla wọnyi di mimọ̀.

Digitized by Google

20 Oluwa, kò si ẹniti o dabi rẹ bẹ̃ni kò
si Ọlọrun miran lẹhin rẹ, gẹgẹ bi gbogbo
eyi ti awa ti fi eti wa gbọ́.
21 Orilẹ-ède kan wo li o wà li aiye ti o
dabi enia rẹ Israeli, ti Ọlọrun lọ irapada
lati ṣe enia on tikararẹ̀, lati ṣe orukọ fun
ara rẹ nipa ohun ti o tobi ti o si lẹ̀ru, ni
lile awọn orilẹ-ède jade kuro niwaju awọn
enia rẹ, ti iwọ ti rapada lati Egipti jade
wá?
22 Nitori awọn enia rẹ Israeli li o ti ṣe
li enia rẹ titi lai; iwọ Oluwa, si di Ọlọrun
wọn.
23 Njẹ nisisiyi Oluwa! jẹ ki ọ̀rọ ti iwọ
ti sọ niti iranṣẹ rẹ, ati niti ile rẹ̀ ki o fi idi
mulẹ lailai, ki iwọ ki o si ṣe bi iwọ ti wi.
24 Ani, jẹ ki o fi idi mulẹ, ki a le ma
gbé orukọ rẹ ga lailai, wipe, Oluwa awọn
ọmọ-ogun li Ọlọrun Israeli, ani Ọlọrun fun
Israeli; si jẹ ki ile Dafidi iranṣẹ rẹ ki o fi
idi mulẹ niwaju rẹ.
25 Nitori iwọ, Ọlọrun mi, ti ṣi iranṣẹ rẹ
li eti po, Iwọ o kọ́ ile kan fun u: nitorina
ni iranṣẹ rẹ ri i lati gbadua niwaju rẹ.
26 Njẹ nisisiyi Oluwa, Iwọ li Ọlọrun,
iwọ si ti sọ ọ̀rọ ore yi fun iranṣẹ rẹ;
27 Njẹ nisisyi jẹ ki o wù ọ lati bukún
ile iranṣẹ rẹ, ki o le ma wà niwaju rẹ lai-
lai: nitori iwọ Oluwa, ẹniti o sure fun, ire
ni o si ma jẹ lailai.

## ORI 18.

O SI ṣe lẹhin eyi, ni Dafidi kọlu awọn
ara Filistia, o si ṣẹ́ wọn, o si gbà Gati
ati ilu rẹ̀ lọwọ awọn ara Filistia.
2 O si kọlu Moabu, awọn ara Moabu si
di iranṣẹ Dafidi, nwọn si mu ọrẹ wá.
3 Dafidi si kọlu Hadareseri ọba Soba ni
Hamati bi o ti nlọ lati fi idi ijọba rẹ̀ mulẹ
leti odò Ferate.
4 Dafidi si gbà ẹgbẹrun kẹkẹ́, ati ọ̃dẹ-
gbãrun ẹlẹṣin, ati ẹgbãwa ẹlẹsẹ lọwọ rẹ̀:
Dafidi si já iṣan ẹsẹ gbogbo awọn ẹṣin kẹkẹ́
na, ṣugbọn o pa ọgọrun ẹṣin kẹkẹ́ mọ ninu
wọn.
5 Nigbati awọn ara Siria ti Damasku
wá lati ran Hadareseri ọba Soba lọwọ,
Dafidi pa ẹgbã mọkanla enia ninu awọn
ara Siria.
6 Dafidi si fi ẹgbẹ-ogun si Siria ti Da-
masku; awọn ara Siria si di iranṣẹ Dafidi,
nwọn si mu ọrẹ wá. Bayi li Oluwa gbà
Dafidi nibikibi ti o ba nlọ.
7 Dafidi si gbà awọn asa wura ti mbẹ
lara awọn iranṣẹ Hadareseri, o si mu wọn
wá si Jerusalemu.
8 Lati Tibhati pẹlu ati lati Kuni, ilu
Hadareseri ni Dafidi ko ọ̀pọlọpọ idẹ, eyiti
Solomoni fi ṣe okun idẹ, ọwọ̀n wọnni, ati
ohun-elo idẹ wọnni.
9 Nigbati Tou ọba Hamati gbọ́ pe Dafidi
ti pa gbogbo ogun Hadareseri ọba Soba.
10 O ran Hadoramu ọmọ rẹ̀ si Dafidi
ọba lati ki i ati lati yọ̀ fun u, nitoriti o ti
ba Hadareseri jà o si ti ṣẹgun rẹ̀; (nitori
Tou ti jẹ ọta Hadareseri) o si ni oniruru
ohun-èlo wura ati ti fadakà ati idẹ pẹlu rẹ̀.
11 Awọn pẹlu ni Dafidi yà si mimọ́ fun
Oluwa pẹlu fadakà ati wura ti o ko lati
ọdọ gbogbo orilẹ-ède wọnni wá; lati Edo-
mu, ati lati Moabu, ati lati ọdọ awọn ọmọ
Ammoni, ati lati ọdọ awọn ara Filistia, ati
lati Amaleki wá.
12 Pẹlupẹlu Abiṣai ọmọ Seruiah pa
ẹgbãsan ninu awọn ara Edomu li afonifoji
Iyọ̀.
13 O si fi ẹgbẹ-ogun si Edomu: ati gbo-
gbo awọn ara Edomu si di iranṣẹ Dafidi.
Bayi li Oluwa ngbà Dafidi nibikibi ti o
ba nlọ.
14 Bẹ̃ ni Dafidi jọba lori gbogbo Israeli,
o si ṣe idajọ ati otitọ larin awọn enia rẹ̀.
15 Joabu ọmọ Seruiah si wà lori ogun;
ati Jehoṣafati ọmọ Ahiludi ni akọwe-iranti.
16 Sadoku ọmọ Ahitubu, ati Abimeleki
ọmọ Abiatari, li awọn alufa; ati Ṣafṣa ni
akọwe;
17 Benaiah ọmọ Jehoiada li o si wà lori
awọn Kereti ati awọn Peleti; awọn ọmọ
Dafidi si li olori lọdọ ọba.

## ORI 19.

O SI ṣe lẹhin eyi, ni Nahaṣi ọba awọn
ọmọ Ammoni kú, ọmọ rẹ̀ si jọba ni
ipò rẹ̀.
2 Dafidi si wipe, Emi o ṣe ore fun Ha-
nuni ọmọ Nahaṣi, nitoriti baba rẹ̀ ṣe ore
fun mi. Dafidi si ran onṣẹ lati tù u ninu
nitori baba rẹ̀. Bẹ̃ni awọn iranṣẹ Dafidi
wá si ilẹ awọn ọmọ Ammoni, si ọdọ Hanuni
lati tù u ninu.
3 Ṣugbọn awọn ijoye awọn ọmọ Ammoni
wi fun Hanuni pe, Iwọ rò pe Dafidi bu ọlá
fun baba rẹ nitori ti o ran awọn olutunu si
ọ? Kò ṣepe awọn iranṣẹ rẹ̀ wá si ọdọ rẹ
lati rin wò, ati lati bi ṣubu ati lati ṣe amí
ilẹ na?
4 Nitorina Hanuni kó awọn iranṣẹ Da-
fidi, o si fa irungbọn wọn, o si ké agbáda
wọn sunmọ ibadi wọn, o rán wọn lọ.
5 Nigbana ni awọn kan lọ, nwọn si sọ
fun Dafidi bi a ti ṣe awọn ọkọnrin na: on

Digitized by Google

si ranṣẹ lọ ipade wọn: nitori oju tì awọn
ọkọnrin na gidigidi. Ọba si wipe, Ẹ duro
ni Jeriko titi irungbọn nyin yio fi hù,
nigbana ni ki ẹ si pada wá.
6 Nigbati awọn ọmọ Ammoni ri pe nwọn
ti ba ara wọn jẹ lọdọ Dafidi, Hanuni ati
awọn ọmọ Ammoni ran ẹgbẹrun talenti
fadakà lati bẹwẹ kẹkẹ́ ati ẹlẹsin lati Siria
ni Mesopotamia wá, ati lati Siria-Maaka
wá, ati lati Soba wá.
7 Bẹ̃ni nwọn bẹwẹ ẹgbã mẹrindilogun
kẹkẹ́ ati ọba Maaka ati awọn enia rẹ̀; nwọn
si wá nwọn si do niwaju Medeba. Awọn
ọmọ Ammoni si ko ara wọn jọ lati ilu wọn,
nwọn si wá si ogun.
8 Nigbati Dafidi gbọ́, o ran Joabu ati
gbogbo ogun awọn akọni enia.
9 Awọn ọmọ Ammoni si jade wá, nwọn
si tẹ ogun niwaju ẹnu-ibode ilu na: awọn
ọba ti o wá si wà li ọtọ̀ ni igbẹ.
10 Nigbati Joabu ri pe a doju ija kọ on,
niwaju ati lẹhin, o yàn ninu gbogbo ãyo
Israeli, o si tẹ ogun wọn si awọn ara
Siria.
11 O si fi iyokù awọn enia le Abiṣai
arakọnrin rẹ̀ lọwọ, nwọn si tẹ ogun si awọn
ọmọ Ammoni.
12 On si wipe, Bi awọn ara Siria ba le
jù fun mi, nigbana ni iwọ o ràn mi lọwọ:
ṣugbọn bi awọn ọmọ Ammoni ba le jù fun
ọ, nigbana li emi o ràn ọ lọwọ.
13 Ṣe giri ki o si jẹ ki a huwa akọni fun
enia wa ati fun ilu Ọlọrun wa: ki Oluwa
ki o si ṣe eyi ti o dara loju rẹ̀.
14 Bẹ̃ni Joabu ati awọn enia ti o wà
pẹlu rẹ̀ sún siwaju awọn ara Siria si ibi
ija: nwọn si sá niwaju rẹ̀.
15 Nigbati awọn ọmọ Ammoni si ri pe
awọn ara Siria sá, awọn pẹlu sá niwaju
Abiṣai arakọnrin rẹ̀, nwọn si wọ̀ ilu lọ.
Nigbana ni Joabu wá si Jerusalemu.
16 Nigbati awọn ara Siria ri pe a le wọn
niwaju Israeli, nwọn ran onṣẹ, nwọn si fà
awọn ara Siria ti mbẹ lòke odò: Ṣofaki
olori ogun Hadareseri sì ṣiwaju wọn.
17 A si sọ fun Dafidi; on si ko gbogbo
Israeli jọ, o si gòke odò Jordani, o si yọ si
wọn, o si tẹ ogun si wọn. Bẹ̃ni nigbati
Dafidi tẹ ogun si awọn ara Siria nwọn ba
a jà.
18 Ṣugbọn awọn ara Siria sá niwaju
Israeli, Dafidi si pa ẹ̃dẹgbarin enia ninu
awọn ara Siria ti o wà ninu kẹkẹ́, ati ọkẹ-
meji ẹlẹsẹ, o si pa Ṣofaki olori ogun na.
19 Nigbati awọn iranṣẹ Hadareseri ri pe
a le wọn niwaju Israeli, nwọn ba Dafidi
làja, nwọn si nsìn i: bẹ̃ni awọn ara Siria
kò jẹ ràn awọn ọmọ Ammoni lọwọ mọ.

## ORI 20.

OSI ṣe lẹhin igbati ọdun yipo, li akokò
ti awọn ọba lọ si ogun; Joabu si gbé
agbara ogun jade, o si ba ilu awọn ọmọ
Ammoni jẹ, nwọn si wá, nwọn si do tì
Rabba. Ṣugbọn Dafidi duro ni Jerusalemu.
Joabu si kọlù Rabba o si pa a run.
2 Dafidi si gbà ade ọba wọn kuro lori
rẹ̀, o si ri i pe o wọ̀n talenti wura kan,
okuta iyebiye si wà lara rẹ̀; a si fi de
Dafidi li ori: o si kó ikogun pipọpipọ lati
inu ilu na wá.
3 O si kó awọn enia ti o wà nibẹ jade
wá, o si fi ayùn ati irin mimu ati ãke ké
wọn. Ani bayi ni Dafidi ṣe si gbogbo ilu
awọn ọmọ Ammoni. Ati Dafidi ati gbogbo
awọn enia pada bọ̀ si Jerusalemu.
4 O si ṣe lẹhin eyi li ogun si de ni Geseri
pẹlu awọn ara Filistia; li akokò na ni Sib-
bekai ara Huṣa pa Sippai, ti inu awọn ọmọ
òmiran: a si tẹ ori wọn ba.
5 Ogun si tun wà pẹlu awọn ara Filistia;
Elhanani ọmọ Jairi si pa Lahamu arakọn-
rin Goliati ara Gati, igi ọ̀kọ rẹ̀ si dabi ìti
awunṣọ.
6 Ogun si tun wà ni Gati, nibiti ọkọnrin
gigun kan gbe wà, ika ati ọmọ-ẹsẹ ẹniti o
jẹ mẹrinlelogun, mẹfa li ọwọ kọkan, ati
mẹfa li ẹsẹ kọkan, a si bi i pẹlu fun
òmiran.
7 Ṣugbọn nigbati o pe Israeli ni ija,
Jonatani ọmọ Ṣimea arakọnrin Dafidi pa a.
8 Awọn wọnyi li a bi fun òmiran ni
Gati; nwọn si tipa ọwọ Dafidi ṣubu, ati
ipa ọwọ awọn iranṣẹ rẹ̀.

## ORI 21.

SATANI si duro tì Israeli, o si tì Dafidi
lati ka iye Israeli.
2 Dafidi si wi fun Joabu ati awọn olori
enia pe, Lọ ikaye Israeli lati Beerṣeba titi
de Dani; ki o si mu iye wọn fun mi wá, ki
emi ki o le mọ̀ iye wọn.
3 Joabu si wipe, Ki Oluwa ki o mu
awọn enia rẹ̀ pọ̀ si i ni igba ọgọrun jù bi
wọn ti wà: ọba, oluwa mi, gbogbo wọn kì
iha ṣe iranṣẹ oluwa mi? ẽṣe ti oluwa mi fi
mbère nkan yi? ẽṣe ti on o fi mu Israeli
jẹbi.
4 Ṣugbọn ọ̀rọ ọba bori ti Joabu, nitorina
Joabu jade lọ, o si la gbogbo Israeli ja, o si
de Jerusalemu.
5 Joabu si fi apapọ iye awọn enia na fun

Digitized by Google

Dafidi. Gbogbo Israeli jasi ẹgbẹrun ẹgbẹ-
run ati ọke marun enia ti nkọ idà: Juda
si jasi ọkẹ mẹtalelogun le ẹgbãrun ọkọnrin
ti nkọ idà.
6 Ṣugbọn Lefi ati Benjamini ni kò kà
pẹlu wọn: nitori ọ̀rọ ọba jẹ irira fun
Joabu.
7 Nkan yi si buru loju Ọlọrun; o si
kọlù Israeli.
8 Dafidi si wi fun Ọlọrun pe, Emi ti ṣẹ̀
gidigidi ni ṣiṣe nkan yi: ṣugbọn nisisiyi,
emi bẹ̀ ọ, mu ẹ̀ṣẹ iranṣẹ rẹ kuro; nitoriti
mo hùwa wère gidigidi.
9 Oluwa si wi fun Gadi, ariran Dafidi
pe,
10 Lọ ki o si wi fun Dafidi pe, Bayi li
Oluwa wi, mo fi nkan mẹta lọ̀ ọ: yàn ọkan
ninu wọn ki emi ki o le ṣe e si ọ.
11 Bẹ̃ni Gadi tọ Dafidi wá, o si wi fun u
pe, Bayi li Oluwa wi, yan fun ara rẹ,
12 Yala ọdun mẹta iyan, tabi iparun li
oṣù mẹta niwaju awọn ọta rẹ, ti idà awọn
ọta rẹ nle ọ ba; tabi idà Oluwa, ni ijọ
mẹta, ani ajakalẹ àrun ni ilẹ na, ti angeli
Oluwa o ma pani ja gbogbo àgbegbe Israeli.
Njẹ nisisiyi rò o wò, esi wo ni emi o mu
pada tọ̀ ẹniti o ran mi.
13 Dafidi si wi fun Gadi pe, iyọnu nla
ba mi: jẹ ki emi ki o ṣubu si ọwọ Oluwa
nisisiyi: nitori ãnu rẹ̀ pọ̀; ṣugbọn má jẹ
ki emi ṣubu si ọwọ ẹnia.
14 Bẹ̃ li Oluwa ran ajakalẹ arun si Is-
raeli: awọn ti o ṣubu ni Israeli jẹ ẹgbã
marundilogoji enia.
15 Ọlọrun si ran angeli kan si Jerusa-
lemu lati run u: bi o si ti nrun u, Oluwa
wò, o si kãnu nitori ibi na, o si wi fun
angeli na ti nrun u pe; O to, da ọwọ rẹ
duro. Angeli Oluwa na si duro nibi ilẹ-
ipaka Ọrnani, ara Jebusi.
16 Dafidi si gbé oju rẹ̀ soke, o si ri
angeli Oluwa na dura lagbedemeji aiye ati
ọrun, o ni idà fifayọ lọwọ rẹ̀ ti o si nà sori
Jerusalemu. Nigbana ni Dafidi ati awọn
àgbagba Israeli, ti o wọ aṣọ ọ̀fọ, da oju
wọ́n bolẹ.
17 Dafidi si wi fun Ọlọrun pe, Emi kọ́
ha paṣẹ lati kaye awọn enia? ani emi li
ẹniti o ṣẹ̀ ti mo si ṣe buburu pãpã; ṣugbọn
bi o ṣe ti agutan wọnyi, kini nwọn ṣe?
Emi bẹ̀ ọ, Oluwa Ọlọrun mi, jẹ ki ọwọ rẹ
ki o wà li ara mi, ati lara ile baba mi; ṣu-
gbọn ki o máṣe li ara awọn enia rẹ ti a o fi
arùn kọlu wọn.
18 Nigbana ni angeli Oluwa na paṣẹ fun
Gadi lati sọ fun Dafidi pe, ki Dafidi ki o
gòke lọ ki o si tẹ pẹpẹ kan fun Oluwa, ni
ilẹ ipaka Ornani, ara Jebusi.
19 Dafidi si gòke lọ nipa ọ̀rọ Gadi, ti o
sọ li orukọ Oluwa.
20 Ornani si yipada, o si ri angeli na;
ati awọn ọmọ rẹ̀ mẹrin pẹlu rẹ̀ pa ara wọn
mọ́. Njẹ Ornani npa ọka lọwọ.
21 Bi Dafidi si ti de ọdọ Ornani, Ornani
si wò, o si ri Dafidi, o si ti ibi ilẹ ipaka rẹ̀
jade, o si wọlẹ, o dojubolẹ fun Dafidi.
22 Dafidi si wi fun Ornani pe, Fun mi
ni ibi ipaka yi, ki emi ki o le tẹ pẹpẹ kan
nibẹ fun Oluwa; iwọ o si fi fun mi ni iye
owo rẹ̀ pipe; ki a le da ajakalẹ arun duro
lọdọ awọn enia.
23 Ornani si wi fun Dafidi pe, Mu u fun
ra rẹ, si jẹ ki oluwa mi ọba ki o ṣe eyiti o
dara loju rẹ̀: wò o mo fi awọn malu pẹlu
fun ẹbọ-ọrẹ-sisun, ati ohun-èlo ipaka fun
igi, ati ọka fun ọrẹ-onjẹ; mo fi gbogbo rẹ̀
fun ọ.
24 Dafidi ọba si wi fun Ornani pe,
Bẹ̃kọ; ṣugbọn emi o rà a ni iye owo rẹ̀
pipe nitõtọ, nitoriti emi kì o mu eyi ti iṣe
tirẹ fun Oluwa, bẹ̃ni emi kì o ru ẹbọ-ọrẹ
sisun laiṣe inawo.
25 Bẹ̃ni Dafidi fi ẹgbẹta ṣekeli wura nipa
ìwọn fun Ornani fun ibẹ na.
26 Dafidi si tẹ pẹpẹ kan nibẹ fun Oluwa,
o si ru ẹbọ ọrẹ-sisun ati ẹbọ ọpẹ, o si kepe
Oluwa; on si fi iná da a li ohùn lati ọrun
wá lori pẹpẹ ẹbọ-ọrẹ sisun na.
27 Oluwa si paṣẹ fun angeli na; on si
tun tẹ ida rẹ̀ bọ inu akọ rẹ̀.
28 Li akokò na nigbati Dafidi ri pe
Oluwa ti da on li ohùn ni ibi ilẹ-ipaka
Ornani, ara Jebusi, o si rubọ nibẹ.
29 Nitori agọ Oluwa ti Mose pa li agin-
ju, ati pẹpẹ ọrẹ sisun, mbẹ ni ibi giga ni
Gibeoni li akokò na.
30 Ṣugbọn Dafidi kò le ilọ siwaju rẹ̀ lati
bere lọwọ Ọlọrun: nitoriti ẹ̀ru idà angeli
Oluwa na ba a.

## ORI 22.

NIGBANA ni Dafidi wipe, Eyi ni ile
Oluwa Ọlọrun, eyi si ni pẹpẹ ọrẹ-
sisun fun Israeli.
2 Dafidi si paṣẹ lati ko awọn alejo ti mbẹ
ni ilẹ Israeli jọ; o si yan awọn agbẹkuta
lati gbẹ okuta lati fi kọle Ọlọrun.
3 Dafidi si pese irin li ọ̀pọlọpọ fun iṣo
fun ilẹkun ẹnu-ọ̀na, ati fun ìde; ati idẹ li
ọ̀pọlọpọ li aini iwọn;
4 Igi kedari pẹlu li ainiye: nitori awọn

Digitized by Google

ara Sidoni, ati awọn ti Tire mu ọ̀pọlọpọ igi
kedari wá fun Dafidi.
5 Dafidi si wipe, Solomoni ọmọ mi, ọdọ-
mọde ni, o si rọ̀, ile ti a o si kọ́ fun Oluwa,
a o si ṣe e tobi jọjọ, fun okiki ati ogo ka
gbogbo ilẹ: nitorina emi o pese silẹ fun
u. Bẽni Dafidi si pese silẹ lọpọlọpọ, ki o
to kú.
6 Nigbana li o pe Solomoni ọmọ rẹ̀, o si
fi aṣẹ fun u lati kọ́le kan fun Oluwa Ọlọrun
Israeli.
7 Dafidi si wi fun Solomoni pe, Ọmọ mi,
bi o ṣe ti emi ni, o ti wà li ọkàn mi lati
kọ́le kan fun orukọ Oluwa Ọlorun mi:
8 Ṣugbọn ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá, wipe,
Iwọ ti ta ẹ̀jẹ silẹ li ọ̀pọlọpọ, iwọ si ti ja
ogun nlanla: iwọ kò gbọdọ kọ́ ile fun
orukọ mi, nitoriti iwọ ta ẹ̀jẹ pipọ̀ silẹ
niwaju mi.
9 Kiyesi i, a o bi ọmọ kan fun ọ, ẹniti
yio ṣe enia isimi; emi o si fun u ni isimi
lọdọ gbogbo awọn ọta rẹ̀ yika kiri: nitori
orukọ rẹ̀ yio ma jẹ Solomoni, emi o si fi
alafia ati idakẹjẹ fun Israeli li ọjọ aiye rẹ̀.
10 On o kọ ile kan fun orukọ mi; on
o si jẹ ọmọ mi; emi o si jẹ baba fun u;
emi o si fi idi itẹ ijọba rẹ̀ mulẹ lori Israeli
lailai.
11 Njẹ ọmọ mi, ki Oluwa ki o pẹlu rẹ;
iwọ si ma pọ̀ si i, ki o si kọ́ ile Oluwa
Ọlọrun rẹ, bi o ti sọ nipa tirẹ.
12 Kiki ki Oluwa ki o fun ọ li ọgbọ́n
ati oye, ki o si fun ọ li aṣẹ niti Israeli,
ki iwọ ki o le pa ofin Oluwa Ọlọrun rẹ
mọ́.
13 Nigbana ni iwọ o ma pọ̀ si i, bi iwọ
ba ṣe akiyesi lati mu aṣẹ ati idajọ ti Oluwa
pa fun Mose ṣẹ niti Israeli: mura giri ki o
si ṣe onigboya, má bẹ̀ru bẽni ki aiya ki o
máṣe fò ọ.
14 Si kiyesi i, ninu ipọnju mi, emi ti
pèse fun ile Oluwa na, ọkẹ marun talenti
wura, ati ẹgbẹrun ẹgbẹrun talenti fadakà;
ati ti idẹ, ati ti irin, laini ìwọn; nitori
ọ̀pọlọpọ ni: ati ìti-igi ati okuta ni mo ti
pèse; iwọ si le wá kún u.
15 Pẹlupẹlu awọn onişẹ mbẹ fun ọ lọpọ-
lọpọ, awọn gbẹnagbẹna ati awọn onişọna
okuta ati igi ati onirũru ọlọgbọ́n enia fun
onirũru iṣẹ.
16 Niti wura, fadakà ati idẹ, ati irin, kò
ni ìwọn. Nitorina dide ki o si ma şişẹ, ki
Oluwa ki o si pẹlu rẹ.
17 Dafidi paṣẹ pẹlu fun gbogbo awọn
ijoye Israeli lati ran Solomoni ọmọ rẹ̀ lọwọ
pe:
18 Oluwa Ọlọrun nyin kò ha wà pẹlu
nyin? on kò ha ti fi isimi fun nyin niha
gbogbo? on sa ti fi awọn ti ngbe ilẹ na le
mi li ọwọ; a si ṣẹgun ilẹ na niwaju Oluwa
ati niwaju enia rẹ̀.
19 Njẹ nisisiyi ẹ fi aiya nyin ati ọkàn
nyin si atiwá Oluwa Ọlọrun nyin; nitorina
dide ki ẹ si kọ́ ibi mimọ́ Oluwa Ọlọrun,
lati mu apoti ẹri ti majẹmu Oluwa wọ̀ inu
rẹ̀, ati ohun-èlo mimọ́ Ọlọrun, sinu ile na
ti a o kọ́ fun orukọ Oluwa.

## ORI 23.

NIGBATI Dafidi gbó, ti o si kún fun ọjọ,
o fi Solomoni ọmọ rẹ̀ jẹ ọba lori
Israeli.
2 O si kó gbogbo awọn ijoye Israeli jọ,
ati awọn alufa ati awọn ọmọ Lefi.
3 A si ka awọn omọ Lefi lati ẹni ọgbọ̀n
ọdun ati jù bẹ̃ lọ: iye wọn nipa ori wọn,
ọkọnrin kọkan si jẹ ẹgbã mọkandilogun.
4 Ninu wọnyi, ẹgbã mejila ni lati ma
bojuto iṣẹ ile Oluwa; ẹgbãta si nṣe olori
ati onidajọ:
5 Ẹgbaji si jẹ adena: ẹgbaji si fi ohun-
elo ti mo ṣe lati buyìn, yìn Oluwa.
6 Dafidi si pín wọn ni ẹgbẹgbẹ lãrin
awọn ọmọ Lefi, eyini ni Gerşoni, Kohati,
ati Merari.
7 Ninu awọn ọmọ Gerşoni ni Laadani,
ati Şimei.
8 Awọn ọmọ Laadani: Jehieli ni olori,
ati Setamu, ati Joeli, mẹta.
9 Awọn ọmọ Şimei; Şelomiti, ati Ha-
sieli, ati Harani, mẹta. Awọn wọnyi li
olori awọn baba Laadani.
10 Awọn ọmọ Şimei ni Jahati, Sina, ati
Jeuşi, ati Beriah. Awọn mẹrin wọnyi li
ọmọ Şimei.
11 Jahati si li olori, ati Sisa ibikeji:
şugbọn Jeuşi ati Beriah kò li ọmọ pipọ;
nitorina ni nwọn ṣe wà ni işiro kan, gẹgẹ
bi ile baba wọn.
12 Awọn ọmọ Kohati; Amramu, Ishari,
Hebroni ati Ussieli, mẹrin.
13 Awọn ọmọ Amramu; Aaroni ati
Mose: a si ya Aaroni si ọ̀tọ, ki o le ma sọ
awọn ohun mimọ́ jùlọ di mimọ́, on ati
awọn ọmo rẹ̀ lailai, lati ma jo turari niwa-
ju Oluwa, lati ma ṣe iranṣẹ fun u, ati lati
ma sure li orukọ rẹ̀ lailai.
14 Şugbọn niti Mose enia Ọlọrun, a kà
awọn ọmọ rẹ̀ pọ̀ mọ ẹ̀ya Lefi.
15 Awọn ọmọ Mose ni, Gerşomu ati
Elieseri.

Digitized by Google

16 Ninu awọn ọmọ Gerṣomu, Sebueli li
olori.
17 Awọn ọmọ Elieseri ni Rehabiah olori.
Elieseri kò si li ọmọ miran ; ṣugbọn awọn
ọmọ Rehabiah pọ̀ gidigidi.
18 Ninu awọn ọmọ Ishari ; Ṣelomiti li
olori.
19 Ninu awọn ọmọ Hebroni : Jeriah
ekini, Amariah ekeji, Jahasieli ẹkẹta, ati
Jekamami ẹkẹrin.
20 Ninu awọn ọmọ Ussieli : Mika ekini,
ati Jesiah ekeji.
21 Awọn ọmọ Merari ; Mali ati Muṣi.
Awọn ọmọ Mali ; Eleasari ati Kiṣi.
22 Eleasari kú, kò si li ọmọkọnrin bi-
kòṣe ọmọbirin : awọn arakọnrin wọn awọn
ọmọ Kiṣi si fẹ wọn li aiya.
23 Awọn ọmọ Muṣi ; Mali, ati Ederi,
ati Jeremoti, mẹta.
24 Wọnyi ni awọn ọmọ Lefi, bi ile baba
wọn ; ani olori awọn baba, bi a ti ka wọn
ni iye orukọ, nipa ori wọn, awọn ti o ṣiṣọ
ìsin ile Oluwa, lati iwọn ogun ọdun ati jù
bẹ̃ lọ.
25 Nitori Dafidi wipe, Oluwa Ọlọrun
Israeli ti fi isimi fun awọn enia rẹ̀, on si
ngbé Jerusalemu lailai :
26 Ati pẹlu awọn ọmọ Lefi : nwọn kì
yio si tun rù ibugbe na mọ, ati gbogbo
ohun-elo rẹ̀ fun ìsin rẹ̀.
27 Nitori nipa ọ̀rọ ikẹhin Dafidi, ni kika
iye awọn ọmọ Lefi lati ìwọn ogun ọdun ati
jù bẹ̃ lọ :
28 Nitori iṣẹ wọn ni lati duro tì awọn
ọmọ Aaroni, fun ìsin ile Oluwa, niti àgbala,
ati niti iyẹwu, ati niti ṣiṣe ohun èlo wonni
ni mimọ́, ati iṣẹ ìsin ile Ọlọrun.
29 Ati fun àkara ifihàn, ati fun iyẹfun
kikuna fun ẹbọ ọrẹ, ati fun àkara alaiwu,
ati fun eyi ti a yan ninu awo pẹtẹ, ati fun
eyi ti a dín, ati fun gbogbo oniruru òṣuwọn
ati ìwọn ;
30 Ati lati duro li orowurọ lati dupẹ ati
lati yìn Oluwa, ati bẹ̃ gẹgẹ li aṣalẹ ;
31 Ati lati ru gbogbo ẹbọ ọrẹ sisun fun
Oluwa li ọjọjọ isimi, ati li oṣù titun ati li
ọjọ wọnni ti a pa li aṣẹ, ni iye, li ẹsẹsẹ gẹgẹ
bi aṣẹ ti a pa fun wọn nigba-gbogbo niwa-
ju Oluwa :
32 Ati ki nwọn ki o ma tọju ẹṣọ agọ ajọ
enia, ati ẹṣọ ibi mimọ́, ati ẹṣọ awọn ọmọ
Aaroni arakọnrin won, ni ìsin ile Oluwa.

ORI 24.

NJẸ bi a ti pín awọn ọmọ Aaroni ni
wọnyi. Awọn ọmọ Aaroni ; Nabadu
ati Abihu, Eleasari, ati Itamari.
2 Ṣugbọn Nadabu ati Abihu kú ṣaju
baba wọn, nwọn kò si li ọmọ : nitorina ni
Eleasari ati Itamari fi ṣiṣẹ alufa.
3 Dafidi si pin wọn, ati Sadoku ninu
awọn ọmọ Eleasari, ati Ahimeleki ninu
awọn ọmọ Itamari, gẹgẹ bi iṣẹ wọn ninu
ìsin wọn.
4 A si ri awọn ọkọnrin ti o nṣe olori
ninu awọn ọmọ Eleasari jù ti inu awọn
ọmọ Itamari lọ, bayi li a si pin wọn.
Ninu awọn ọmọ Eleasari, ọkọnrin mẹrindi-
logun li o nṣe olori ni ile baba wọn, ati
mẹjọ ninu awọn ọmọ Itamari, gẹgẹ bi ile
baba wọn.
5 Bayi li a fi iṣẹkeké pin wọn, iru kan
mọ ikeji pẹlu ; nitori awọn olori ibi mimọ́,
ati olori ti Ọlọrun wà ninu awọn ọmọ
Eleasari, ati ninu awọn ọmọ Itamari.
6 Ati Ṣemaiah ọmọ Nataneeli akọwe,
ọkan ninu awọn ọmọ Lefi kọ wọn niwaju
ọba, ati awọn olori, ati Sadoku alufa, ati
Ahimeleki, ọmọ Abiatari, ati niwaju olori
awọn baba awọn alufa, ati awọn ọmọ Lefi :
a mu ile baba kan fun Eleasari, a si mu
ọkan fun Itamari.
7 Njẹ iṣẹkeké ekini jade fun Jehoiaribu,
ekeji fun Jedaiah,
8 Ẹkẹta fun Harimu, ẹkẹrin fun Seori-
mu,
9 Ẹkarun fun Malkijah, ẹkẹfa fun Mi-
jamini,
10 Ekeje fun Hakkosi, ẹkẹjọ fun Abijah,
11 Ẹkẹsan fun Jeṣua, ẹkẹwa fun Ṣeka-
niah,
12 Ẹkọkanla fun Eliaṣibu, ekejila fun
Jakimu,
13 Ẹkẹtala fun Huppa, ẹkẹrinla fun
Jeṣebeabu,
14 Ẹkẹdogun fun Bilga, ẹkẹrindilogun
fun Immeri,
15 Ẹkẹtadilogun fun Heṣiri, ekejidilo-
gun fun Afisesi,
16 Ẹkọkandilogun fun Petahiah, ogun
fun Jehesekeli,
17 Ẹkọkanlelogun fun Jakini, ekejilelo-
gun fun Gamuli,
18 Ẹkẹtalelogun fun Delaiah, ẹkẹrinle-
logun fun Maasiah.
19 Wọnyi ni itò wọn ni ìsin wọn lati lọ
sinu ile Oluwa, gẹgẹ bi iṣe wọn nipa ọwọ

Digitized by Google

Aaroni baba wọn, bi Oluwa Ọlọrun Israeli
ti paṣẹ fun u.
20 Iyokù awọn ọmọ Lefi ni wọnyi:
Ninu awọn ọmọ Amramu; Ṣubaeli: ninu
awọn ọmọ Ṣubaeli; Jehediah.
21 Nipa ti Rehabiah; ninu awọn ọmọ
Rehabiah, ekini Isṣiah.
22 Ninu awọn Ishari; Ṣelomoti; ninu
awọn ọmọ Ṣelomoti; Jahati.
23 Awọn ọmọ Hebroni: Jeriah ikini;
Amariah ekeji, Jahasieli ẹkẹta, Jekamamu
ẹkẹrin.
24 Awọn ọmọ Ussieli; Mika: awọn ọmọ
Mika; Ṣamiri.
25 Arakonrin Mika ni Iṣṣiah; ninu
awọn ọmọ Isṣiah; Sekariah.
26 Awọn ọmọ Merari ni Mali ati Muṣi:
awọn ọmọ Jaasiah; Beno;
27 Awọn ọmọ Merari nipa Jaasiah;
Beno ati Ṣohamu, ati Sakkuri, ati Ibri.
28 Lati ọdọ Mali ni Eleasari ti wá, ẹniti
kò li ọmọkọnrin.
29 Nipa ti Kiṣi: ọmọ Kiṣi ni Jerameeli.
30 Awọn ọmọ Muṣi pẹlu; Mali, ati
Ederi, ati Jerimoti. Wọnyi li ọmọ awọn
ọmọ Lefi nipa ile baba wọn.
31 Awọn wọnyi pẹlu ṣẹ keké gẹgẹ bi
awọn arakọnrin wọn awọn ọmọ Aaroni
niwaju Dafidi ọba ati Sadoku, ati Ahime-
leki, ati awọn olori awọn baba awọn alufa
ati awọn ọmọ Lefi: olori awọn baba gẹgẹ
bi aburo rẹ̀.

## ORI 25.

PẸLUPẸLU Dafidi ati awọn olori ogun
yà ninu awọn ọmọkọnrin Asafu, ati
Hemani, ati Jedutuni, fun ìsin yi, awọn
ẹniti o ma fi dura ati psalteri, ati kimbali
kọrin: ati iye awọn oniṣẹ gẹgẹ bi ìsin wọn
jẹ:
2 Ninu awọn ọmọ Asafu, Sukkuri, ati
Josefu, ati Netaniah, ati Asarela, awọn
ọmọ Asafu, abẹ ọwọ Asafu, ti o kọrin gẹgẹ
bi aṣẹ ọba.
3 Ti Jedutuni: awọn ọmọ Jedutuni;
Gedaliah, ati Seri, ati Jeṣaiah, Haṣabiah,
ati Mattitiah, ati Ṣimei, mẹfa, labẹ ọwọ
baba wọn Jedutuni, ẹniti o fi duru kọrin,
lati ma dupẹ fun ati lati ma yìn Oluwa.
4 Ti Hemani: awọn ọmọ Hemani:
Bukkiah, Mattaniah, Ussieli, Ṣebueli, ati
Jerimotu, Hananiah, Hanani, Eliata, Gid-
dalti, ati Romamtieseri, Joṣbekaṣa, Malloti,
Hotiri, Mahasiotu:
5 Gbogbo awọn wọnyi li awọn ọmọ He-
mani, woli ọba ninu ọ̀rọ Ọlọrun, lati ma
gbé iwo na soke. Ọlọrun si fun Hemani li
ọmọkọnrin mẹrinla ati ọmọbirin mẹta.
6 Gbogbo awọn wọnyi li o wà labẹ ọwọ
baba wọn, fun orin ile Oluwa, pẹlu kimba-
li, psalteri ati duru, fun ìsin ile Ọlọrun:
labẹ ọwọ ọba, ni Asafu, Jedutuni, ati He-
mani wà.
7 Bẹ̃ni iye wọn, pẹlu awọn arakọnrin
wọn ti a kọ́ li orin Oluwa, ani gbogbo awọn
ti o moye, jasi ọrinlugba o le mẹjọ.
8 Nwọn si ṣẹ keké fun iṣẹ; gbogbo wọn
bakanna bi ti ẹni-kekere bẹ̃ni ti ẹni-nla, ti
olukọ bi ti ẹniti a nkọ́.
9 Iṣẹkeké ekini si jade wá fun Asafu si
Josefu: ekeji si Gedaliah, ẹniti on pẹlu
awọn arakọnrin rẹ̀ ati awọn ọmọ rẹ̀, jẹ
mejila:
10 Ẹkẹta si Sakkuri, awọn ọmọ rẹ̀ ati
awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
11 Ẹkẹrin si Isri, awọn ọmọ rẹ̀, ati awọn
arakọnrin rẹ̀, jẹ, mejila:
12 Ẹkarun si Netaniah, awọn ọmọ rẹ̀,
ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
13 Ẹkẹfa si Bukkiah, awọn ọmọ rẹ̀, ati
awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila.
14 Ekeje si Jeṣarela, awọn ọmọ rẹ̀, ati
awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
15 Ẹkẹjọ si Jeṣaiah, awọn ọmọ rẹ̀, ati
awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
16 Ẹkẹsan si Mattaniah, awọn ọmọ rẹ̀,
ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
17 Ẹkẹwa si Ṣimei, awọn ọmọ rẹ̀, ati
awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
18 Ẹkọkanla si Asareeli, awọn ọmọ rẹ̀,
ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
19 Ekejila si Haṣabiah, awọn ọmọ rẹ̀,
ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
20 Ẹkẹtala si Ṣubaeli, awọn ọmọ rẹ̀, ati
awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
21 Ẹkẹrinla si Mattitiah, awọn ọmọ rẹ̀,
ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
22 Ẹkẹ̃dogun si Jeremoti, awọn ọmọ rẹ̀,
ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
23 Ẹkẹrindilogun si Hananiah, awọn
ọmọ rẹ̀ ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
24 Ẹkẹtadilogun si Joṣbekaṣa awọn ọmọ
rẹ̀, ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
25 Ekejidilogun si Hanani, awọn ọmọ
rẹ̀, ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
26 Ẹkọkandilogun si Malloti, awọn ọmọ
rẹ̀, ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
27 Ogun si Eliata, awọn ọmọ rẹ̀, ati
awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
28 Ẹkọkanlelogun si Hotiri, awọn ọmọ
rẹ̀, ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:

Digitized by Google

Ekejilelogun si Giddalti, awọn ọmọ
. awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
Ẹkẹtalelogun si Mahasioti, awọn ọmọ
. awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila:
Ẹkẹrinlelogun si Romamti-eseri, awọn
ẹ̀, ati awọn arakọnrin rẹ̀, jẹ mejila.

## ORI 26.

I ipin awọn adena: niti awọn ọmọ
Kosa ni Meṣelemiah ọmọ Kore, ninu
ọmọ Asafu.
ıti awọn ọmọ Meṣelemiah ni Sekariah
, Jediaeli ekeji, Sebadiah ẹkẹta, Jatni-
ẹrin,
:lamu ẹkarun, Johanani ẹkẹfa, Elio-
keje.
ıwọn ọmọ Obed-Edomu si ni Ṣemaiah
, Jehosabadi ekeji, Joa ẹkẹta, ati
i ẹkẹrin, ati Netaneeli ẹkarun,
ımmieli ẹkẹfa, Issakari ekeje, Peulltai
: Ọlọrun sa bukún u.
ıti fun Ṣemaiah ọmọ rẹ̀ li a bi awọn
ti nṣe olori ni ile baba wọn: nitori
ara akọni enia ni nwọn.
ıwọn ọmọ Ṣemaiah; Otni, ati Refaeli,
)bedi, Elsabadi, arakọnrin ẹniti iṣe
ara enia, Elihu, ati Semakiah.
ɜbogbo wọnyi ti inu awọn ọmọ Obed-
ıu ni: awọn, ati awọn ọmọ wọn, ati
arakọnrin wọn, akọni enia ati ala-
ı fun ìsin na, jẹ mejilelọgọta lati ọdọ
-Edomu.
Meṣelemiah si ni awọn ọmọ ati arakọn-
ılagbara enia, mejidilogun.
Hosa pẹlu, ninu awọn ọmọ Merari, ni
; Simri olori (nitori bi on kì iti iṣe
i, ṣugbọn baba rẹ̀ fi jẹ olori),
Hilkiah ekeji, Tebaliah ẹkẹta, Seka-
ẹkẹrin: gbogbo awọn ọmọ ati awọn
ọnrin Hosa jẹ mẹtala.
Ninu awọn wọnyi ni ipin awọn ade-
.ni ninu awọn orori ọkọnrin, ti nwọn
ẹ gẹgẹ bi awọn arakọnrin wọn, lati ṣe
ẹ ni ile Oluwa.
Nwọn si ṣẹ keké, bi ti ẹni-kekere bẹ̃ni
i-nla, gẹgẹ bi ile baba wọn, fun oluku-
ẹnu-ọ̀na.
Iṣẹ keké iha ila-õrun bọ̀ sọdọ Ṣele-
ı. Nigbana ni nwọn ṣẹ keké fun
riah ọmọ rẹ̀, ọlọgbọ́n igbimọ; iṣẹ keké
bọ si iha ariwa.
Sọdọ Obed-Edomu niha gusù; ati
awọn ọmọ rẹ̀ niha ile Asuppimu (yara
).
Ti Suppimu ati Hosa niha ìwọ-õrùn
li ẹnu-ọ̀na Ṣalleketi, nibi ọ̀na igòke lọ, iṣọ
kọju si iṣọ.
17 Niha ìla-õrùn awọn ọmọ Lefi mẹfa
(nṣọ), niha ariwa mẹrin li ojojumọ, niha
gusù mẹrin li ojojumọ, ati ninu Asuppimu
(ile iṣura) mejimeji.
18 Ni ibasa niha iwọ-õrùn, mẹrin li ọ̀na
igòke-lọ ati meji ni ibasa.
19 Wọnyi ni ipin awọn adena lati inu
awọn ọmọ Kore, ati lati inu awọn ọmọ
Merari.
20 Lati inu awọn ọmọ Lefi, Ahijah li o
wà lori iṣura ile Ọlọrun, ati lori iṣura nkan
wọnni ti a yà si mimọ́.
21 Awọn ọmọ Laadani; awọn ọmọ Laa-
dani ara Gerṣoni, awọn olori baba, ani ti
Laadani ara Gerṣoni ni Jehieli.
22 Awọn ọmọ Jehieli; Setamu, ati Joeli
arakọnrin rẹ̀, ti o wà lori iṣura ile Oluwa.
23 Ninu ọmọ Amramu, ati ọmọ Ishari,
ara Hebroni, ati ọmọ Ussieli:
24 Ati Ṣebueli ọmọ Gerṣomu, ọmọ Mose,
ni onitọju iṣura.
25 Ati awọn arakọnrin rẹ̀ nipa Elieseri,
Rehabiah ọmọ rẹ̀, ati Jesaiah ọmọ rẹ̀, ati
Joramu ọmọ rẹ̀, ati Sikri ọmọ rẹ̀, ati Ṣelo-
miti ọmọ rẹ̀.
26 Ṣelomiti yi ati awọn arakọnrin rẹ̀ li o
wà lori iṣura ohun iyà-si-mimọ́, ti Dafidi
ọba ati awọn olori baba, awọn ijoye lori
ẹgbẹgbẹrun, ati ọrọrun, ati awọn ọlọri ogun
ti yà-si-mimọ́.
27 Lati inu ikogun ti a kó li ogun, ni
nwọn yà si mimọ́ lati ma fi ṣe itọju ile
Oluwa.
28 Ati gbogbo eyiti Samueli, ariran, ati
Saulu, ọmọ Kiṣi, ati Abneri ọmọ Neri, ati
Joabu ọmọ Seruiah, yà si mimọ́; gbogbo
ohun ti a ba ti yà si mimọ́, ohun na mbẹ li
ọwọ Ṣelomiti, ati awọn arakọnrin rẹ̀.
29 Ninu awọn ọmọ Ishari, Kenaniah ati
awọn ọmọ rẹ̀ li o jẹ ijoye ati onidajọ fun iṣẹ
ilu lori Israeli.
30 Ninu awọn ọmọ Hebroni, Hasabiah
ati awọn arakọnrin rẹ̀, awọn akọni enia,
ọ̃dẹgbẹsan li awọn alabojuto Israeli nihahin
Jordani niha iwọ-õrun, fun gbogbo iṣẹ
Oluwa, ati fun ìsin ọba.
31 Ninu awọn ọmọ Hebroni ni Jerijah
olori, ani ninu awọn ọmọ Hebroni, gẹgẹ bi
idile ati iran awọn baba rẹ̀. Li ogoji ọdun
ijọba Dafidi, a wá wọn, a si ri ninu wọn,
awọn alagbara akọni enia ni Jaseri ti
Gileadi.
32 Ati awọn arakọnrin rẹ̀, awọn akọni
enia, jẹ ẹgbã o le ọ̃dẹgbẹrin: gbogbo wọn



Digitized by Google

jẹ awọn olori baba ti Dafidi ọba fi ṣe olori lori awọn ọmọ Rubeni, ati awọn ọmọ Gadi, ati àbọ ẹ̀ya Manasse, fun gbogbo ọ̀ran ti Ọlọrun ati ti ọba.

## ORI 27.

NJẸ awọn ọmọ Israeli nipa iye wọn, eyini ni, awọn olori baba, ati awọn balogun ẹgbẹgbẹrun, ati ọrọrun, ati awọn ijoye wọn ti nsin ọba ni olukuluku ọ̀na li ẹgbẹgbẹ, ti nwọle ti si njade li oṣoṣù ni gbogbo oṣù ọdun, jẹ́ ẹgbã mejila.

2 Lori ẹgbẹ kini ti oṣù kini ni Jaṣobeamu ọmọ Sabdieli: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

3 Ninu awọn ọmọ Peresi on ni olori fun gbogbo awọn olori ogun ti ọṣù ekini.

4 Ati lori ẹgbẹ ti oṣù keji ni Dodai ara Ahohi, ati ẹgbẹ tirẹ̀; Mikloti pẹlu nṣe balogun: ẹgbã mejila li o wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀ pẹlu.

5 Olori ogun kẹta fun oṣù kẹta ni Benaiah ọmọ Jehoiada alufa, olori kan: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

6 Eyini ni Benaiah na, akọni enia, ninu awọn ọgbọ̀n, o si jẹ olori awọn ọgbọ̀n: Ammisabadi ọmọ rẹ̀ si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

7 Olori ogun kẹrin fun oṣù kẹrin ni Asaheli arakọnrin Joabu, ati Sebadiah ọmọ rẹ̀ lẹhin rẹ̀: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

8 Olori ogun karun fun oṣù karun ni Ṣamhuti ara Israhi: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

9 Olori ogun kẹfa fun oṣù kẹfa ni Ira ọmọ Ikkeṣi ara Tekoi: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

10 Olori ogun keje fun oṣù keje ni Heleṣi ara Peloni, ninu awọn ọmọ Efraimu: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

11 Olori ogun kẹjọ fun oṣù kẹjọ ni Sibbekai ara Huṣati ti awọn ara Sarehi: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

12 Olori ogun kẹsan fun oṣù kẹsan ni Abieseri ara Anatoti ti awọn ara Benjamini: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

13 Olori ogun kẹwa fun oṣù kẹwa ni Maharai ara Netofa, ti awọn ara Sarehi: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

14 Olori ogun kọkanla fun oṣù kọkanla ni Benaiah ara Peratoni, ti awọn ọmọ Efraimu: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

15 Olori ogun kejila fun oṣù kejila ni Heldai ara Netofa, ti Otnieli: ẹgbã mejila li o si wà ninu ẹgbẹ tirẹ̀.

16 Ati lori awọn ẹ̀ya Israeli: ijoye lori awọn ọmọ Reubeni ni Elieseri ọmọ Sikri: lori awọn ọmọ Simeoni, Ṣefatiah ọmọ Maaka:

17 Lori awọn ọmọ Lefi, Haṣabiah ọmọ Kemueli: lori awọn ọmọ Aaroni, Sadoku:

18 Lori Juda, Elihu, ọkan ninu awọn arakọnrin Dafidi: lori Issakari, Omri ọmọ Mikaeli:

19 Lori Sebuloni, Iṣmaiah ọmọ Obadiah: lori Naftali, Jerimoti ọmọ Asrieli:

20 Lori awọn ọmọ Efraimu, Hoṣea ọmọ Asasiah: lori àbọ ẹ̀ya Manasse, Joeli ọmọ Pedaiah.

21 Lori àbọ ẹ̀ya Manasse ni Gileadi, Iddo ọmọ Sekariah: lori Benjamini, Jaasieli ọmọ Abneri.

22 Lori Dani, Asareeli ọmọ Jerohamu. Awọn wọnyi li olori awọn ẹ̀ya Israeli.

23 Ṣugbọn Dafidi kò ka iye awọn ti o wà lati ogun ọdun ati awọn ti kò to bẽ; nitori ti Oluwa ti wipe, on o mu Israeli pọ̀ si i bi irawọ oju ọrun.

24 Joabu ọmọ Ṣeruiah bẹ̀rẹ si ikà wọn, ṣugbọn kò kà wọn tan, nitori ibinu ṣubu lu Israeli nitori na; bẽni a kò fi iye na sinu iwe Kronika ti Dafidi ọba.

25 Lori awọn iṣura ọba ni Asmafeti ọmọ Adieli wà: ati lori iṣura oko, ni ilu, ati ni ileto, ati ninu odi ni Jonatani ọmọ Ussiah wà:

26 Ati lori awọn ti nro oko, lati ma ro ilẹ ni Esri ọmọ Kelubi wà:

27 Ati lori awọn ọgba-àjara ni Ṣimei ara Ramoti wà: lori eso ọgba-àjara fun iṣura ati ọti-waini ni Sabdi ọmọ Ṣifmi wà:

28 Ati lori igi-olifi, ati igi-sikamore ti mbẹ ni pẹtẹlẹ ni Baal-hanani ara Gederi wà; ati lori iṣura ororo ni Joaṣi wà.

29 Ati lori awọn agbo malu ti njẹ̀ ni Ṣaroni ni Ṣitiai ara Ṣaroni wà: ati lori agbo malu ti o wà li afonifoji ni Ṣafati ọmọ Adlai wà:

30 Ati lori ibakasiẹ ni Obili ara Iṣmaeli wà: ati lori abo kẹtẹkẹtẹ ni Jehodaiah ara Meronoti wà:

31 Ati lori agbo agutan ni Jasisi ara Hageri wà. Gbogbo awọn wọnyi ni ijoye ohun ini ti iṣe ti Dafidi ọba.

32 Jonatani ẹgbọn Dafidi pẹlu ni ìgbimọ ọlọgbọ́n enia ati akọwe: ati Jehueli ọmọ Hakmoni wà pẹlu awọn ọmọ ọba.

33 Ahitofeli si jẹ ìgbimọ ọba: ati Huṣai ara Arki ni ọrẹ ọba.

Digitized by Google

34 Ati lẹhin Ahitofeli ni Jehoiada ọmọ
Benaiah, ati Abiatari: Joabu si ni arẹ-
balogun ogun ọba.

ORI 28.

DAFIDI si kó gbogbo ijoye Israeli jọ,
awọn ijoye ẹ̀ya, ati awọn ijoye awọn
ẹgbẹ ti nṣe iranṣẹ fun ọba, ati awọn ijoye
lori ẹgbẹgbẹrun, ati awọn ijoye lori ọrọrun,
ati awọn ijoye lori gbogbo ọrọ̀ ati ini ọba,
ati ti awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu awọn balogun, ati
pẹlu awọn alagbara enia, ati gbogbo akọni
enia si Jerusalemu.
2 Nigbana ni Dafidi ọba dide duro li ẹsẹ
rẹ̀, o si wipe, Ẹ gbọ́ ti emi, ẹnyin arakọnrin
mi ati enia mi: emi fẹ li ọkàn mi lati kọ́
ile isimi kan fun apoti-ẹri majẹmu Oluwa,
ati fun itisẹ Ọlọrun wa, mo si ti mura tan
fun kikọ́le na:
3 Ṣugbọn Ọlọrun sọ fun mi pe, Iwọ kò
gbọdọ kọ́ ile fun orukọ mi, nitori ologun
ni iwọ, o si ti ta ẹ̀jẹ silẹ.
4 Oluwa Ọlọrun Israeli si yàn mi lati
inu gbogbo ile baba mi lati jẹ ọba lori
Israeli lailai: nitori ti o ti yàn Juda li
olori; ati ninu ile Juda, ile baba mi: ati
larin awọn ọmọ baba mi o fẹ mi lati jẹ ọba
gbogbo Israeli.
5 Ati ninu gbogbo ọmọ mi ọkọnrin (ni-
tori ti Oluwa ti fun mi li ọmọkọnrin pupọ),
o ti yàn Solomoni ọmọ mi lati joko lori itẹ
ijọba Oluwa lori Israeli.
6 On si wi fun mi pe, Solomoni ọmọ rẹ,
on yio kọ́ ile mi ati agbala mi: nitori emi
ti yàn a li ọmọ mi, emi o si jẹ baba fun u.
7 Pẹlupẹlu emi o fi idi ijọba rẹ̀ mulẹ
lailai, bi o ba murale lati ṣe ofin mi ati
idajọ mi bi li oni yi.
8 Njẹ nisisiyi li oju gbogbo Israeli ijọ
enia Oluwa, ati li eti Ọlọrun wa, ẹ ma
pamọ́ ki ẹ si ma ṣafẹri gbogbo ofin Oluwa
Ọlọrun nyin: ki ẹ le ni ilẹ rere yi, ki ẹ si
le fi i silẹ li ogún fun awọn ọmọ nyin lẹhin
nyin lailai.
9 Ati iwọ, Solomoni ọmọ mi, mọ̀ Ọlọrun
baba rẹ, ki o si fi aiya pipé ati fifẹ ọkàn
sin i: nitori Oluwa a ma wá gbogbo aiya,
o si mọ̀ gbogbo ete ironu: bi iwọ ba ṣafẹri
rẹ̀, iwọ o ri i; ṣugbọn bi iwọ ba kọ̀ ọ silẹ,
on o ta ọ nù titi lai.
10 Wò o nisisiyi: nitori Oluwa ti yàn ọ
lati kọ́ ile kan fun ibi mimọ́, mura le, ki
iwọ si ṣe e.
11 Nigbana ni Dafidi fi apẹrẹ fun Solo-
moni ọmọ rẹ̀ ti iloro, ati ti ile rẹ̀, ati ti ibi
iṣura rẹ̀, ati ti iyara-òke rẹ̀, ati ti gbangan
inu rẹ̀ ati ti ibi ibujoko ãnu,
12 Ati apẹrẹ gbogbo eyi ti o ni ni inu rẹ̀
pẹlu rẹ̀ niti agbala ile Oluwa, ati ti gbogbo
iyara yikakiri, niti ibi iṣura ile Ọlọrun, ati
niti ibi iṣura ohun ti a yà-si-mimọ́:
13 Niti ipin awọn alufa pẹlu ati ti awọn
ọmọ Lefi, ati niti gbogbo iṣẹ ìsin ile Oluwa,
ati niti gbogbo ohun-èlo ìsin ni ile Oluwa.
14 Niti wura nipa ìwọn ti wura, niti
gbogbo ohun-èlo oniruru ìsin; niti gbogbo
ohun-èlo fadakà nipa ìwọn, niti gbogbo
ohun-èlo fun oniruru ìsin:
15 Ati ìwọn ọpa fitila wura, ati fitila
wura wọn, nipa ìwọn fun olukuluku ọpa
fitila ati ti fitila rẹ̀: ati niti ọpa fitila fa-
dakà nipa ìwọn, ti olukuluku ọpa fitila ati
ti fitila rẹ̀, gẹgẹ bi ìlo olukuluku ọpa fitila.
16 Ati wura nipa ìwọn fun tabili àkara
ifihan, fun olukuluku tabili; ati fadakà
fun tabili fadakà:
17 Ati wura didara fun pàlaka mimu
ẹran, ati ọpọn, ati ago: ati fun awo-koto
wura nipa ìwọn fun olukuluku awo-koto;
ati nipa ìwọn fun olukuluku awo-koto
fadakà:
18 Ati fun pẹpẹ turari, wura daradara
nipa ìwọn; ati apẹrẹ iduro awọn kerubu ti
wura, ti nwọn nà iyẹ wọn, ti nwọn si bo
apoti ẹri majẹmu Oluwa mọlẹ.
19 Gbogbo eyi wà ninu iwe lati ọwọ
Oluwa ẹniti o kọ́ mi niti gbogbo iṣẹ apẹrẹ
wọnyi.
20 Dafidi si sọ fun Solomoni ọmọ rẹ̀ pe,
murale ki o si gboyà, ki o si ṣiṣẹ: má bẹ̀ru,
bẽni ki o máṣe dãmu: nitori Oluwa Ọlọ-
run, ani Ọlọrun mi wà pẹlu rẹ; on kì yio
yẹ̀ ọ, bẽni kì yio kọ̀ ọ silẹ titi iwọ o fi pari
gbogbo iṣẹ fun ìsin ile Oluwa.
21 Si kiyesi i, ipin awọn alufa ati awọn
ọmọ Lefi, wà pẹlu rẹ fun oniruru ìsin ile
Ọlọrun: iwọ ni pẹlu rẹ oniruru enia, ọlọ-
kàn fifẹ, ẹniti o ni oye gbogbo iṣẹ fun
oniruru iṣẹ: pẹlupẹlu awọn ijoye ati gbo-
gbo awọn enia wà pẹlu rẹ fun gbogbo ọ̀ran
rẹ.

ORI 29.

DAFIDI ọba si wi fun gbogbo ijọ enia
pe, Solomoni ọmọ mi, on nikan ti
Ọlọrun ti yàn, jẹ ọmọde o si rọ̀, iṣẹ na si
tobi: nitori ti ãfin na kì iṣe fun enia, ṣu-
gbọn fun Ọlọrun Oluwa.
2 Ati pẹlu gbogbo ipá mi ni mo ti fi
pèse silẹ fun ile Ọlọrun mi, wura fun ohun

Digitized by Google

ti wura, ati fadakà fun ti fadakà, ati idẹ
fun ti idẹ, irin fun ti irin, ati igi fun ti igi;
okuta oniki ti a o tẹ̀ bọ okuta lati fi ṣe ọṣọ,
ati okuta oniruru àwọ, ati oniruru okuta
iyebiye, ati okuta marbili li ọ̀pọlọpọ.
3 Pẹlupẹlu, nitori ni didùn inu mi si ile
Ọlọrun mi, mo fi ohun ini mi, eyinì ni
wura ati fadakà, fun ile Ọlọrun mi, jù
gbogbo eyi ti mo ti pèse silẹ fun ile mimọ́
na,
4 Ẹgbẽdogun talenti wura, ti wura Ofiri,
ati ọ̀dẹgbãrin talenti fadakà didara, lati fi
bo ogiri ile na:
5 Wura fun ohun èlo wura, ati fadakà
fun ohun èlo fadakà, ati fun oniruru iṣẹ
nipa ọwọ awọn ọlọnà. Tani si nfẹ loni lati
yà ara rẹ̀ si mimọ fun Oluwa?
6 Nigbana ni awọn olori awọn baba ati
awọn ijoye ẹ̀ya Israeli, ati awọn balogun
ẹgbẹgbẹrun ati ọrọrun, pẹlu awọn ijoye iṣẹ
ọba fi tinutinu ṣe iranlọwọ,
7 Nwọn si fi fun iṣẹ ile Ọlọrun, ti wura
ẹgbẽdọgbọ̀n talenti ati ẹgbãrun dramu, ati
ti fadakà ẹgbãrun talenti, ati ti bàba ẹgbã-
san talenti, ati ọkẹ marun talenti irin.
8 Ati awọn ti a ri okuta iyebiye lọdọ
wọn fi i sinu iṣura ile Oluwa, nipa ọwọ
Jehieli ara Gerṣoni.
9 Awọn enia si yọ̀, nitori nwọn fi tinu-
tinu ṣe iranlọwọ nitori pẹlu ọkàn pipe ni
nwọn fi tinutinu ṣe iranlọwọ fun Oluwa:
pẹlupẹlu Dafidi ọba si yọ̀ gidigidi.
10 Nitorina Dafidi fi iyìn fun Oluwa li
oju gbogbo ijọ: Dafidi si wipe, Olubukún
ni Iwọ Oluwa Ọlọrun Israeli baba wa lai
ati lailai!
11 Tirẹ Oluwa ni titobi, ati agbara, ati
ogo, ati iṣẹgun, ati ọlá-nla: nitori ohun
gbogbo li ọrun ati li aiye tirẹ ni; ijọba ni
tirẹ, Oluwa, a si gbé ọ leke li ori fun ohun
gbogbo.
12 Ọrọ̀ pẹlu ati ọlá ọdọ rẹ ni ti iwá, iwọ
si jọba lori ohun gbogbo; li ọwọ rẹ ni
agbara ati ipá wà; ati li ọwọ rẹ ni sisọ ni
di nla wà, ati fifi agbara fun ohun gbogbo.
13 Njẹ nisisiyi, Ọlọrun wa, awa dupẹ
lọwọ rẹ, a si yìn orukọ ogo rẹ.
14 Ṣugbọn tali emi, ati kili awọn enia
mi, ti a fi le ṣe iranlọwọ tinutinu bi iru eyi?
nitori ohun gbogbo ọdọ rẹ ni iti wá, ati ninu
ohun ọwọ rẹ li awa ti fi fun ọ.
15 Nitori alejo ni awa niwaju rẹ, ati
atipo bi gbogbo awọn baba wa: ọjọ wa li
aiye dabi ojiji, kò si si ireti.
16 Oluwa Ọlọrun wa, gbogbo ohun ọ̀pọ-
lọpọ yi ti awa ti pèse silẹ lati kọ ile fun ọ
fun orukọ rẹ mimọ́, lati ọwọ rẹ wá ni, ati
gbogbo rẹ̀ jẹ tirẹ.
17 Emi mọ̀ pẹlu, Ọlọrun mi, pe iwọ ndan
ọkàn wò, iwọ si ni inudidùn si ododo. Bi
o ṣe ti emi, ninu ododo ọkàn mi li emi ti fi
tinutinu ṣe iranlọwọ gbogbo nkan wọnyi;
ati nisisiyi pẹlu ayọ̀ ni mo ti ri awọn enia
rẹ ti o wà nihin, lati fi tinutinu ṣe iran-
lọwọ fun ọ.
18 Oluwa Ọlọrun Abrahamu, Isaaki ati
Israeli, awọn baba wa, pa eyi mọ́ lailai
sinu ete ironu ọkàn awọn enia rẹ, si fi idi
ọkàn wọn mulẹ si ọdọ rẹ:
19 Si fi ọkàn pipe fun Solomoni ọmọ mi
lati pa ofin rẹ, ẹri rẹ, ati ilana rẹ mọ́, ati
lati ṣe ohun gbogbo, ati lati kọ́ ãfin, fun
eyi ti mo ti pèse silẹ.
20 Dafidi si sọ fun gbogbo ijọ enia pe,
Nisisiyi ẹ fi iyìn fun Oluwa Ọlọrun nyin.
Gbogbo enia si fi iyìn fun Oluwa Ọlọrun
awọn baba wọn, nwọn si tẹ ori wọn ba,
nwọn wolẹ fun Oluwa ati ọba.
21 Nwọn si ru ẹbọ si Oluwa, nwọn si ru
ẹbọ sisun si Oluwa, li ọjọ keji lẹhin ọjọ na
ẹgbẹrun akọmalu, ẹgbẹrun àgbo, ẹgbẹrun
ọdọ-agutan, pẹlu ọrẹ mimu wọn, ati ẹbọ
miran li ọ̀pọlọpọ fun gbogbo Israeli:
22 Nwọn si jẹ nwọn si mu niwaju Oluwa
li ọjọ na pẹlu ayọ̀ nla. Nwọn si tun fi
Solomoni ọmọ Dafidi jọba li ẽkeji, a si fi
ororo yàn a li ọba, ati Sadoku li alufa.
23 Bẹ̃ni Solomoni joko lori itẹ Oluwa bi
ọba ni ipò Dafidi baba rẹ̀, o si pọ̀ si i;
gbogbo Israeli si gba tirẹ̀ gbọ́.
24 Ati gbogbo awọn ijoye, ati awọn
alagbara, ati pẹlu gbogbo awọn ọmọ Dafidi
ọba tẹri wọn ba fun Solomoni ọba.
25 Oluwa si gbé Solomoni ga gidigidi li
oju gbogbo Israeli, o si fi ọlá-nla ọba fun
u bi iru eyi ti kò wà fun ọba kan ṣaju rẹ̀
lori Israeli.
26 Dafidi ọmọ Jesse si jọba lori gbogbo
Israeli.
27 Akokò ti o si fi jọba lori Israeli jẹ
ogoji ọdun; ọdun meje li o jọba ni Hebroni,
ati mẹtalelọgbọn li o jọba ni Jerusalemu.
28 On si darugbó, o kú rere, o kún fun
ọjọ, ọrọ̀ ati ọlá; Solomoni ọmọ rẹ̀ si jọba
ni ipò rẹ̀.
29 Njẹ iṣe Dafidi ọba, ibẹ̀rẹ ati ikẹhin,
kiyesi i, a kọ ọ sinu iwe Samueli ariran,
ati sinu iwe itan Natani woli, ati sinu iwe
itan Gadi ariran.
30 Pẹlu gbogbo jijọba ati ipá rẹ̀, ati ìgba
ti o kọja lori rẹ̀, ati lori Israeli, ati lori
gbogbo ijọba ilẹ wọnni.

Digitized by Google

IWE EKEJI TI

# KRONIKA.

## ORI 1.

I mu Solomoni, ọmọ Dafidi, lagbara
lori ijọba rẹ̀, Oluwa Ọlọrun rẹ̀ si wà
rẹ̀, o si gbé e ga gidigidi.
Solomoni si sọ fun gbogbo Israeli, fun
balogun ẹgbẹgbẹrun, ati ọrọrun, ati
awọn onidajọ, ati fun gbogbo awọn
ni gbogbo Israeli, awọn olori awọn

Solomoni ati gbogbo awọn ijọ enia
rẹ̀, lọ si ibi giga ti o wà ni Gibeoni;
i nibẹ ni agọ ajọ enia Ọlọrun gbe wà,
ose, iranṣẹ Oluwa ti pa ni aginju.
Apoti-ẹri Ọlọrun ni Dafidi ti gbé lati
t-jearimu wá si ibi ti Dafidi ti pese
un u, nitoriti o ti pa agọ kan silẹ fun
Jerusalemu.
Ṣugbọn pẹpẹ idẹ ti Besaleeli, ọmọ Uri,
Huri, ti ṣe, wà nibẹ niwaju agọ Oluwa:
noni ati ijọ enia si wá a ri.
Solomoni si lọ si ibi pẹpẹ idẹ niwaju
a, ti o ti wà nibi agọ ajọ, o si rú
un ebọ-sisun lori rẹ̀.
Li oru na li Oluwa fi ara hàn Solo-
, o si wi fun u pe, Bère ohun ti emi o
ọ.
Solomoni si wi fun Ọlọrun pe, Iwọ ti
u nla hàn baba mi, o si ti mu mi jọba
ò rẹ̀.
Nisisiyi Oluwa Olọrun, jẹ ki a mu ọ̀rọ
n Dafidi baba mi ṣẹ: nitoriti iwọ ti fi
ba lori awọn enia ti o pọ̀ bi erupẹ ilẹ.
Fun mi li ọgbọ́n ati ìmọ nisisiyi, ki
le ma wọ ile, ki nsi ma jade niwaju
yi: nitoripe, tani le ṣe idajọ enia rẹ
o pọ̀ to yi.
Ọlọrun si wi fun Solomoni pe, Ni-
i eyi wà li aiya rẹ, ti iwọ kò si bère
ọlà, tabi ọlá, tabi ẹmi awọn ọta rẹ,
o kò tilẹ bère ẹmi gigun, ṣugbọn o
ọgbọ́n fun ara rẹ, ki o le ma ṣe idajọ
mi, lori ẹniti mo fi ọ jọba:
Nitorina a fi ọgbọ́n on ìmọ fun ọ,
o si fun ọ ni ọrọ̀, ọlà, ati ọlá, iru eyiti
kan ninu awọn ti nwọn wà ṣaju rẹ kò
ni ri, bẹ̃ni lẹhin rẹ kì yio si ẹniti yio ni irn
rẹ̀.
13 Solomoni si pada lati ibi giga ti o wà
ni Gibeoni wá si Jerusalemu, lati iwaju agọ
ajọ awọn enia, o si jọba lori Israeli.
14 Solomoni kó kẹkẹ̀ ati awọn ẹlẹṣin,
jọ: o si ni ẹgbãje kẹkẹ́ ati ẹgbãfa ẹlẹṣin, ti
o fi sinu ilu kẹkẹ́ ati pẹlu ọba ni Jeru-
salemu.
15 Ọba si ṣe ki fadakà ati wura ki o wà
ni Jerusalemu bi okuta, ati igi kedari li o
ṣe ki o dabi igi sikamore ti o wà ni afoni-
foji fun ọ̀pọlọpọ.
16 A si mu ẹṣin wá fun Solomoni lati
Egipti, ati okùn-ọ̀gbọ: awọn oniṣowo ọba
ngbà okùn-ọ̀gbọ na ni iye kan.
17 Nwọn si gòke, nwọn si mu kẹkẹ́ kan
lati Egipti wá fun ẹgbẹta ṣekeli fadakà, ati
ẹṣin kan fun ãdọjọ: bẹ̃ni nwọn si nmu ẹṣin
jade fun gbogbo awọn ọba ara Hitti, ati fun
awọn ọba Siria nipa wọn.

## ORI 2.

SOLOMONI si pinnu rẹ̀ lati kọ́ ile kan
fun orukọ Oluwa, ati ile kan fun ijọba
rẹ̀.
2 Solomoni si yàn ẹgbã marundilogoji
ọkọnrin lati ru ẹrù, ati ọkẹ mẹrin lati ké
igi li ori òke, ati egbejidilogun lati bojuto
wọn.
3 Solomoni si ranṣẹ si Huramu, ọba Tire,
wipe, Gẹgẹ bi iwọ ti ba Dafidi, baba mi lò,
ti iwọ fi igi kedari ṣọwọ si i lati kọ́ ile
kan fun u lati ma gbe inu rẹ̀, bẹni ki o ba
mi lò.
4 Kiyesi i, emi nkọ́ ile kan fun orukọ
Oluwa, Ọlọrun mi, lati yà a si mimọ́ fun u,
ati lati sun turari niwaju rẹ̀, ati fun àkara-
ifihan igbakugba, ati fun ẹbọ-sisun li ọwurọ
ati li alẹ, li ọjọjọ isimi ati li oṣoṣù titun,
ati li apejọ Oluwa Ọlọrun wa; eyi ni aṣẹ
fun Israeli titi lai.
5 Ile ti emi nkọ́ yio si tobi; nitori ti-
tobi ni Ọlọrun wa jù gbogbo awọn ọlọrun
lọ.
6 Ṣugbọn tani to lati kọ́ ile fun u, nitori

Digitized by Google

ọrun ati ọrun awọn ọrun kò le gbà a? tali emi ti emi iba kọ́le fun u, bikòṣe kiki ati sun ẹbọ niwaju rẹ̀?

7 Njẹ nisisiyi rán ọkọnrin kan si mi ti o gbọ́n lati ṣiṣẹ ni wura, fadakà, ati ni idẹ, ati ni irin, ati ni èse aluko, ati òdodó ati alaró, ti o si le gbọ́ngbọn ati gbẹgi pẹlu awọn ọkọnrin ọlọgbọ́n ti o wà lọdọ mi ni Juda ati Jerusalemu, awọn ẹniti Dafidi baba mi ti pese silẹ.

8 Fi ìti-igi kedari, ati firi, ati algumu ranṣẹ si mi pẹlu, lati Lebanoni wá: emi sa mọ̀ pe awọn iranṣẹ rẹ le gbọ́ngbọn ati ké igi ni Lebanoni; si kiyesi i, awọn ọmọ-ọdọ mi yio wà pẹlu awọn ọmọ-ọdọ rẹ:

9 Ani lati pèse ìti-igi lọpọlọpọ silẹ fun mi: nitori ile na ti emi mura lati kọ́ tobi, o si ya ni lẹnu.

10 Si wò o, emi o fi fun ilo awọn akégi, ti nké ìti-igi, lọwọ awọn ọmọ-ọdọ rẹ, ẹgbã-wa òṣuwọn alikama fun onjẹ, ati ẹgbãwa òṣuwọn barli ati ẹgbãwa bati ọti-waini, ati ẹgbãwa bati ororo.

11 Nigbana ni Huramu, ọba Tire, kọwe dahùn o si ranṣẹ si Solomoni pe, Nitori ti Oluwa fẹran awọn enia rẹ̀ li o ṣe fi ọ jọba lori wọn.

12 Huramu si wipe, Alabukún fun li Oluwa Ọlọrun Israeli, ti o da ọrun on aiye, ẹniti o fun Dafidi ọba ni ọlọgbọ́n ọmọ, ti o mọ̀ ọgbọ́n ati oye, ti o le kọ́ ile fun Oluwa, ati ile fun ijọba rẹ̀.

13 Njẹ nisisiyi emi rán ọkọnrin ọlọgbọ́n kan, ti o mọ̀ oye, ani Huramu-Abi,

14 Ọmọ obirin kan ninu awọn ọmọbirin Dani: baba rẹ̀ si ṣe ọkọnrin ara Tire ti o gbọ́ngbọn ati ṣiṣẹ ni wura, ati ni fadakà, ni idẹ, ni irin, ni okuta, ati ni ìti-igi, ni èse-aluko, ni alaró, ati ni ọ̀gbọ daradara, ati òdodó, lati gbẹ́ oniruru ohun gbigbẹ́ pẹlu, ati lati ṣe awari ìmọ-ẹrọ gbogbo ti a o fi fun u ṣe, pẹlu awọn ọlọgbọ́n rẹ, ati pẹlu awọn ọlọgbọ́n oluwa mi Dafidi, baba rẹ.

15 Njẹ nitorina alikama ati ọka-barli, ororo, ati ọti-waini na ti oluwa mi ti sọ, jẹ ki o fi ranṣẹ si awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀.

16 Awa o si ké igi lati Lebanoni wá, iyekiye ti iwọ o fẹ; awa o si mu wọn fun ọ wá ni fifó li okun si Joppa; iwọ o si rù wọn gòke lọ si Jerusalemu.

17 Solomoni si kaye gbogbo awọn ajeji ọkọnrin ti o wà ni ilẹ Israeli, gẹgẹ bi kikà ti Dafidi baba rẹ̀ ti kà wọn; a si ri pe, awọn jẹ ọkẹ-mẹjọ o di-egbejilelọgbọ́n.

18 O si yàn ẹgbã marundilogoji ninu wọn lati ru ẹrù, ati ọkẹ merin lati se akó-okuta li ori òke, ati egbejidilogun alabojuto lati kó awọn enia ṣiṣẹ.

## ORI 3.

SOLOMONI si bẹ̀rẹ si ikọ́ ile Oluwa ni Jerusalemu li òke Moriah nibiti Ọlọrun farahàn Dafidi baba rẹ̀, ti Dafidi ti pèse, nibi ilẹ-ipaka Ornani, ara Jebusi.

2 On si bẹ̀rẹ si ikọ́ ile ni ọjọ keji oṣù keji, li ọdun kẹrin ijọba rẹ̀.

3 Eyi si ni ìwọn ti Solomoni fi lelẹ fun kikọ́ ile Ọlọrun. Gigùn rẹ̀ ni igbọnwọ gẹgẹ bi ìwọn igbãni li ọgọta igbọnwọ, ati ibu rẹ̀, ogún igbọnwọ.

4 Ati iloro ti mbẹ niwaju ile na, gigùn rẹ̀ ri gẹgẹ bi ibu ile na, ogún igbọnwọ, ati giga rẹ̀ ọgọfa; o si fi kiki wura bò o ninu.

5 O si fi igi-firi bò ile ti o tobi, o si fi wura daradara bò o, o si gbẹ́ àworan igi-ọpẹ ati ẹ̀wọn si i.

6 O si fi okuta iyebiye ṣe ile na li ọṣọ́ fun ẹwà: wura na si jasi wura Parfaimu.

7 O si fi wura bò ile na pẹlu, ati ìti, opó, ati ogiri rẹ̀ wọnni, ati ilẹkun rẹ̀ mejeji; o si gbẹ́ àworan awọn kerubu si ara ogiri na.

8 O si ṣe ile mimọ́-jùlọ na, gigùn eyiti o wà gẹgẹ bi ibu ile na, ogún igbọnwọ: ati ibu rẹ̀, ogún igbọnwọ: o si fi wura daradara bò o, ti o to ẹgbẹta talenti.

9 Oṣuwọn iṣó si jasi ãdọta ṣekeli wura. On si fi wura bò iyara òke wọnni.

10 Ati ninu ile mimọ́-jùlọ na, o ṣe kerubu meji ti iṣẹ ọnà finfin, o si fi wura bò wọn.

11 Iyẹ awọn kerubu na si jẹ ogún igbọnwọ ni gigùn: iyẹ kan jẹ igbọnwọ marun, ti o kan ogiri ile na, iyẹ keji si jẹ igbọnwọ marun, ti o kan iyẹ kerubu keji.

12 Ati iyẹ kerubu keji jẹ igbọnwọ marun ti o kan ogiri ile na: ati iyẹ keji jẹ igbọnwọ marun ti o kan iyẹ kerubu keji.

13 Iyẹ kerubu wọnyi nà jade ni ogún igbọnwọ: nwọn si duro li ẹsẹ wọn, oju wọn si wà kọju si ile.

14 O si ṣe iboju alaro, ati elese-aluko, ati òdodó, ati ọ̀gbọ daradara, o si ṣiṣẹ awọn kerubu lara wọn.

15 O si ṣe ọwọ̀n meji igbọnwọ marundilogoji ni giga niwaju ile na, ati ipari ti mbẹ lori ọkọkan wọn si jẹ igbọnwọ marun.

16 O si ṣe ẹ̀wọn ninu ibi-idahùn na, o si fi wọn si ori awọn ọwọ̀n na: o si ṣe

Digitized by Google

pomegranate ọgọrun, o si fi wọn si
ọn na.
) si gbé awọn ọwọ̀n na ro niwaju ile
ı, ọkan li apa ọtún, ati ekeji li apa
ıi pe orukọ eyi ti mbẹ li apa ọtún ni
, ati orukọ eyi ti mbẹ li apa òsi ni

## ORI 4.

ṣe pẹpẹ idẹ kan, ogún igbọnwọ ni
;igùn rẹ̀, ogún igbọnwọ si ni ibu rẹ̀,
›ọnwọ mẹwa ni giga rẹ̀.
' si ṣe agbada didà nla, igbọnwọ mẹ-
;i eti kan de eti ekeji, o ṣe birikiti,
wọ marun si ni giga rẹ̀ ; okùn ọgbọ̀n
wọ li o si yi i kakiri :
.woran malu si wà labẹ rẹ̀ yi i kakiri,
si lọ yi agbada nla na kakiri : igbọn-
ẹwa yi i ka, ọwọ́ meji malu li a dà ni
vọn kan.
) duro lori malu mejila wọnni, mẹta
ha ariwa, ati mẹta nwò iwọ-õrun, ati
nwò gusu ati mẹta nwò iha ilà-orun :
bé agbada na ka ori wọn, gbogbo iha
wọn si wà ninu.
) si nipọn to ibu atẹlẹwọ, a si fi itan-
i ṣiṣẹ eti rẹ̀ gẹgẹ bi eti ago, o si gbà,
la ẹgbẹdogun ìwọn bati duro.
) ṣe agbada mẹwa pẹlu, o si fi marun
ı ọtún, ati marun si apa òsi, lati wẹ̀
wọn : iru nkan ti nwọn fi nrubọ sisun
vọn nwẹ̀ ninu wọn ; ṣugbọn agbada na
n awọn alufa lati ma wẹ̀.
O si ṣe ọpa-fitila wura mẹwa gẹgẹ bi
; wọn, o si fi wọn sinu tempili, marun
a ọtún, ati marun li apa òsi.
O si ṣe tabili mẹwa, o si fi sinu tempi-
ıarun li apa ọtún, ati marun li apa òsi.
ṣe ọgọrun ọpọ́n wura.
O ṣe agbala awọn alufa pẹlu, ati agbala
ati ilẹkun fun agbala nla na, o si fi idẹ
wẹ meji ilẹkun wọn.
) O si fi agbada na si apa ọtún igun ile
ırun, si idojukọ gusu.
ı Huramu si ṣe ikoko, ati ọkọ́ ati ọpọ́n.
·amu si pari iṣẹ na ti o ni iṣe fun Solo-
ıi ọba ni ile Ọlọrun ;
2 Ọwọ̀n meji ati ọta, ati ọpọ́n ti o wà
ri ọwọ̀n mejeji na, ati iṣẹ ẹ̀wọn ıneji
bò ọta meji ti ọpọ́n na, ti o wà li ori
n ọwọ̀n na ;
3 Ati irinwo pomegranate li ara iṣẹ
ın meji na, ẹsẹ meji pomegranate li ara
ẹ̀wọn kan, lati bò ọta meji na ti ọpọ́n
· wà lori awon ọwọ̀n na.
14 O si ṣe ijoko, o si ṣe agbada li ori
awọn ijoko na.
15 Agbada nla kan, ati malu mejila labẹ
rẹ̀.
16 Ati ikoko ati ọkọ́, ati kọkọrọ-ẹran,
ati gbogbo ohun-elo ni Huramu-Abifi fi idẹ
didan ṣe fun Solomoni ọba, fun ile Oluwa.
17 Ni pẹtẹlẹ Jordani ni ọba dà wọn, ni
ilẹ amọ̀ li agbedemeji Sukkoti ati Seredata.
18 Bayi ni Solomoni ṣe gbogbo ohun-elo
wọnyi li ọ̀pọlọpọ : nitori ti a kò le mọ̀
ìwọn idẹ na.
19 Solomoni si ṣe gbogbo ohun-elo ti iṣe
ti ile Ọlọrun, pẹpẹ wura pẹlu, ati awọn
tabili lori eyi ti akara ifihan wà ;
20 Ọpa-fitila pẹlu ati fitila wọn, ki nwọn
ki o ma jo gẹgẹ bi aṣẹ niwaju ibi-mimọ́-
jùlọ, jẹ wura daradara.
21 Ati itanna, ati fitila ati ẹ̀mu li o fi
wura ṣe ; gbogbo eyi ni wura daradara ;
22 Ati alumagaji fitila, ati awo-koto, ati
ṣibi ati awo-koto turari, wura daradara ni :
ati ọ̀na iwọle, awẹ ilẹkun rẹ̀ ti inu lọhun
fun ibi-mimọ́-jùlọ, ati awọn ilẹkun fun ile
na, ani tempili, wura ni.

## ORI 5.

BAYI ni gbogbo iṣẹ ti Solomoni ṣe fun
ile Oluwa pari : Solomoni si mu gbo-
gbo nkan ti Dafidi baba rẹ̀ ti yà si mimọ́
wá sinu rẹ̀ ; ati fadakà, ati wura, ati gbo-
gbo ohun-elo, li o fi sinu iṣura ile Ọlọrun.
2 Nigbana ni Solomoni pe awọn àgba-
gba Israeli jọ, ati gbogbo olori awọn baba
awọn ọmọ Israeli si Jerusalemu, lati mu
apoti-ẹri majẹmu Oluwa gòke lati ilu Dafi-
di wá, ti iṣe Sioni.
3 Gbogbo awọn ọkọnrin Israeli si pejọ
sọdọ ọba li ajọ, eyi ni oṣù keji.
4 Gbogbo awọn àgbagba Israeli si wá ;
awọn ọmọ Lefi si gbé apoti-ẹri na.
5 Nwọn si gbé apoti-ẹri na gòke, ati agọ
ajọ, ati gbogbo ohun-elo mimọ́ ti o wà
ninu agọ, wọnyi ni awọn alufa ati awọn
ọmọ Lefi mu gòke wá.
6 Solomoni ọba, ati gbogbo ijọ enia
Israeli ti o pejọ si ọdọ rẹ̀, wà niwaju apoti-
ẹri na, nwọn si fi agutan ati malu rubọ, ti
a kò le kà, bẹ̃ni a kò le mọ̀ iye wọn fun
ọ̀pọlọpọ.
7 Awọn alufa si gbé apoti-ẹri ti majẹmu
Oluwa wá si ipò rẹ̀, si ibi-idahùn ile na
sinu ibi-mimọ́-jùlọ, labẹ iyẹ awọn kerubu :
8 Bẹ̃ni awọn kerubu nà iyẹ wọn bò ibi
apoti-ẹri na, awọn kerubu si bò apoti-ẹri
na, ati awọn ọpa rẹ̀ lati òke wá

Digitized by Google

9 Ọpa rẹ̀ wọnni si gùn tobẹ̃, ti a fi ri ori awọn ọpa na lati ibi apoti-ẹri na niwaju ibi mimọ́-jùlọ na, ṣugbọn a kò ri wọn li ode. Nibẹ li o si wà titi di oni yi.

10 Kò si ohun kan ninu apoti-ẹri na bikòṣe walã meji ti Mose fi sinu rẹ̀ ni Horebu, nigbati Oluwa fi ba awọn ọmọ Israeli dá majẹmu, nigbati nwọn ti Egipti jade wá.

11 O si ṣe, nigbati awọn alufa ti ibi mimọ́ jade wá; (nitori gbogbo awọn alufa ti a ri li a yà si mimọ́, nwọn kò si kiyesi ipa wọn nigbana:

12 Awọn ọmọ Lefi pẹlu ti iṣe akọrin, gbogbo wọn ti Asafu, ti Hemani, ti Jedutuni, pẹlu awọn ọmọ wọn ati awọn arakọnrin wọn, nwọn wọ ọ̀gbọ fifun, nwọn ni kimbali, ati ohun-elo orin, ati duru, nwọn si duro ni igun ila-õrun pẹpẹ na, ati pẹlu wọn, iwọn ọgọfa alufa ti nwọn nfún ipè:)

13 O si ṣe bi ẹnipe ẹnikan, nigbati a gbọ́ ohùn awọn afunpè ati awọn akọrin, bi ohùn kan lati ma yìn, ati lati ma dupẹ fun Oluwa; nigbati nwọn si gbé ohùn wọn soke pẹlu ipè ati kimbali, ati ohun-elo orin, lati ma yìn Oluwa pe, O ṣeun; ãnu rẹ̀ si duro lailai: nigbana ni ile na kún fun awọsanma, ani ile Oluwa;

14 Tobẹ̃ ti awọn alufa kò le duro lati siṣẹ ìsin nitori awọsanma na: nitori ogo Oluwa kún ile Ọlọrun.

## ORI 6.

NIGBANA ni Solomoni wipe, Oluwa ti wipe, on o ma gbe inu òkunkun biribiri.

2 Ṣugbọn emi ti kọ́ ile ibugbe kan fun ọ, ati ibi kan fun ọ lati ma gbe titi lai.

3 Ọba si yi oju rẹ̀, o si fi ibukún fun gbogbo ijọ awọn enia Israeli; gbogbo ijọ awọn enia Israeli si dide duro.

4 O si wipe, Olubukún li Oluwa Ọlọrun Israeli, ti o ti fi ọwọ rẹ̀ mu eyi ti o ti fi ẹnu rẹ̀ sọ fun Dafidi baba mi ṣẹ, wipe,

5 Lati ọjọ ti emi ti mu awọn enia mi jade kuro ni ilẹ Egipti, emi kò yán ilu kan ninu gbogbo ẹ̀ya Israeli lati kọ́ ile, ki orukọ mi ki o wà nibẹ; bẹ̃ni emi kò yàn ọkọnrin kan lati ṣe olori Israeli awọn enia mi:

6 Ṣugbọn emi ti yàn Jerusalemu, ki orukọ mi ki o le wà nibẹ; mo si ti yàn Dafidi lati wà lori Israeli, enia mi.

7 O si ti wà li ọkàn Dafidi, baba mi, lati kọ́ ile fun orukọ Oluwa Ọlọrun Israeli:

8 Oluwa si sọ fun Dafidi baba mi pe, nitoriti o wà li ọkàn rẹ lati kọ́ ile fun orukọ mi, iwọ ṣeun li eyiti o wà li ọkàn rẹ.

9 Sibẹ iwọ kò gbọdọ kọ́ ile na; ṣugbọn ọmọ rẹ ti yio jade ti inu rẹ wá ni yio kọ́ ile na fun orukọ mi.

10 Oluwa si ti mu ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ ti o ti sọ; emi si dide ni ipò Dafidi baba mi, a si gbé mi ka itẹ́ Israeli bi Oluwa ti ṣe ileri, emi si ti kọ́ ile na fun orukọ Oluwa Ọlọrun Israeli.

11 Ati ninu rẹ̀ ni mo fi apoti-ẹri na si, ninu eyiti majẹmu Oluwa wà, ti o ba awọn ọmọ Israeli dá.

12 On si duro niwaju pẹpẹ Oluwa, niwaju gbogbo ijọ enia Israeli, o si tẹ ọwọ rẹ̀ mejeji.

13 Nitori Solomoni ṣe aga idẹ kan, igbọnwọ marun ni gigùn, ati igbọnwọ marun ni gbigboro, ati igbọnwọ mẹta ni giga, o si gbé e si ãrin agbala na; lori rẹ̀ li o duro, o si kunlẹ lori ẽkun rẹ̀ niwaju gbogbo ijọ enia Israeli, o si tẹ́ ọwọ rẹ̀ mejeji soke ọrun,

14 O si wipe, Oluwa Ọlọrun Israeli, kò si Ọlọrun ti o dabi rẹ li ọrun tabi li aiye: ti npa majẹmu mọ́, ati ãnu fun awọn iranṣẹ rẹ, ti nfi tọkàntọkan wọn rìn niwaju rẹ.

15 Iwọ ti o ti ba iranṣẹ rẹ Dafidi baba mi, pa eyi ti iwọ ti ṣe ileri fun u mọ́; ti iwọ si ti fi ẹnu rẹ sọ, ti iwọ si ti fi ọwọ rẹ mu u ṣẹ, bi o ti ri loni yi.

16 Njẹ nisisiyi, Oluwa Ọlọrun Israeli, ba iranṣẹ rẹ Dafidi, baba mi pa eyi ti iwọ ti ṣe ileri fun u mọ́, wipe, A kì yio fẹ ọkọnrin kan kù li oju mi lati joko lori itẹ́ Israeli: kiki bi awọn ọmọ rẹ ba kiyesi ọ̀na wọn, lati ma rìn ninu ofin mi, bi iwọ ti rìn niwaju mi.

17 Njẹ nisisiyi, Oluwa Ọlọrun Israeli, jẹ ki ọ̀rọ rẹ ki o ṣẹ, ti iwọ ti sọ fun Dafidi, iranṣẹ rẹ,

18 Ni otitọ ni Ọlọrun yio ha ma ba enia gbe li aiye? Kiyesi i, ọrun ati ọrun awọn ọrun kò le gbà ọ; ambọsi ile yi ti emi kọ́!

19 Sibẹ, iwọ ṣe afiyesi adura iranṣẹ rẹ, ati ẹ̀bẹ rẹ̀, Oluwa Ọlọrun mi, lati tẹtisilẹ si ẹkun ati adura ti iranṣẹ rẹ ngbà niwaju rẹ:

20 Ki oju rẹ ki o le ṣí si ile yi lọsan ati loru, ani si ibi ti iwọ ti wipe, iwọ o fi orukọ rẹ sibẹ; lati tẹtisilẹ si adura ti iranṣẹ rẹ ngbà si ibi yi.

21 Nitorina gbọ́ ẹ̀bẹ iranṣẹ rẹ, ati ti Israeli enia rẹ ti nwọn o ma gbà si ibi yi:

Digitized by Google

ọ́ lati ibugbe rẹ wá, ani lati ọrun
gbati iwọ ba gbọ́, ki o si dariji.
Bi ọkọnrin kan ba ṣẹ̀ si ẹnikeji rẹ̀, ti
ibura le e lati mu u bura, ti ibura
si de iwaju pẹpẹ rẹ ni ile yi ;
Nigbana ni ki o gbọ́ lati ọrun wá, ki
ki o si dajọ awọn iranṣẹ rẹ, ni sisan
ẹnia buburu, lati mu ọ̀na rẹ̀ pada sori
ararẹ̀ ; ati ni didare fun olododo, lati
gẹgẹ bi ododo rẹ̀.
Bi a ba si fọ́ awọn enia rẹ Israeli
iwaju ọta, nitori ti nwọn ti dẹṣẹ si
nwọn ba si pada ti nwọn si jẹwọ
rẹ, ti nwọn si gbadura, ti nwọn si
iwaju rẹ ni ile yi ;
Nigbana ni ki o gbọ́ lati ọrun wá, ki
ari ẹ̀ṣẹ Israeli enia rẹ jì, ki o si mu
ada wá si ilẹ ti iwọ ti fi fun wọn ati
wọn baba wọn.
Nigbati a ba se ọrun mọ́ ti kò si sí
itoriti nwọn ti dẹṣẹ si ọ ; ṣugbọn bi
ba gbadura si ibi yi, ti nwọn ba jẹwọ
rẹ, ti nwọn ba yipada kuro ninu ẹ̀ṣẹ
nitoriti iwọ pọn wọn loju.
Nigbana ni ki o gbọ́ li ọrun, ki o si
ṣẹ awọn iranṣẹ rẹ ji, ati ti Israeli enia
gbati iwọ ba ti kọ́ wọn li ọ̀na rere na,
eyiti nwọn o ma rìn : ki o si rọ òjo
rẹ, ti iwọ ti fi fun awọn enia rẹ ni

Bi ìyan ba mu ni ilẹ, bi àjakalẹ-arun
, bi irẹ̀danu ba wà, tabi eṣú ti njẹrun,
ọn ọta wọn ba yọ wọn li ẹnu ni ilẹ ilu
oniruru ipọnju tabi oniruru àrun.
Adura ki adura, tabi ẹ̀bẹ ki ẹ̀bẹ ti a
ọdọ ẹnikẹni gbà, tabi ọdọ gbogbo
li enia rẹ̀, nigbati olukuluku ba mọ̀
u rẹ̀, ati ibanujẹ rẹ̀, ti o ba si tẹ́ ọwọ
ẹjeji siha ile yi :
Ki iwọ ki o gbọ́ lati ọrun, ibugbe rẹ
ki o si dariji, ki o si san a fun olu-
ku gẹgẹ bi gbogbo ọ̀na rẹ̀, bi iwọ ti
ọkàn rẹ̀ ; (nitori iwọ nikanṣoṣo li o mọ̀
awọn ọmọ enia :)
Ki nwọn ki o le bẹ̀ru rẹ, lati ma rìn li
ẹ, li ọjọ gbogbo ti nwọn o wà ni ilẹ ti
fi fun awọn baba wa.
Pẹlupẹlu niti alejo, ti kì iṣe inu Isra-
nia rẹ, ṣugbọn ti o ti ilẹ òkere jade
itori orukọ nla rẹ, ati ọwọ agbara rẹ
inà apa rẹ ; bi nwọn ba wá ti nwọn ba
adura siha ile yi :
Ki iwọ ki o gbọ́ lati ọrun, ani lati
be rẹ wá, ki o si ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti
na kepe ọ si ; ki gbogbo enia aiye ki o
ọ orukọ rẹ, ki nwọn ki o si le ma bẹ̀ru
rẹ, bi Israeli enia rẹ, ki nwọn ki o le mọ̀
pe orukọ rẹ li a npè mọ ile yi ti emi kọ́.
34 Bi awọn enia rẹ ba jade lọ si ogun si
ọta wọn li ọ̀na ti iwọ o rán wọn, ti nwọn
ba si gbadura si ọ, siha ilu yi, ti iwọ ti yàn,
ati ile ti emi ti kọ́ fun orukọ rẹ :
35 Ki iwọ ki o gbọ́ adura wọn ati ẹ̀bẹ
wọn lati ọrun wa, ki o si mu ọ̀ran wọn
duro.
36 Bi nwọn ba ṣẹ̀ si ọ (nitoriti kò si enia
kan ti kì iṣẹ̀,) bi iwọ ba si binu si wọn, ti
o si fi wọn le awọn ọta lọwọ, ti nwọn ba si
kó wọn ni igbekun lọ si ilẹ ti o jìna rére,
tabi ti o wà nitosi.
37 Ṣugbọn, bi nwọn ba rò inu ara wọn
wò, ni ilẹ nibiti a gbe kó wọn ni igbekun
lọ, ti nwọn ba si yipada, ti nwọn ba si gba-
dura si ọ li oko ẹrú wọn, wipe, Awa ti dẹṣẹ,
awa ti ṣiṣe, awa si ti ṣe buburu :
38 Bi nwọn ba si fi gbogbo aiya ati gbo-
gbo ọkàn wọn yipada si ọ li oko ẹrú wọn,
si ibi ti a gbe kó wọn lọ, ti nwọn ba si
gbadura siha ilẹ wọn, ti iwọ ti fi fun awọn
baba wọn, ati siha ilu na ti iwọ ti yàn, ati
siha ile na ti emi ti kọ́ fun orukọ rẹ :
39 Ki iwọ ki o gbọ́ adura wọn ati ẹ̀bẹ
wọn lati ọrun wá, ani lati ibugbe rẹ wá, ki
o si mu ọ̀ran wọn duro, ki o si dari ẹ̀ṣẹ̀
awọn enia rẹ jì ti nwọn ti da si ọ.
40 Nisisiyi Ọlọrun mi, jẹ ki oju rẹ ki o
ṣí, ki o si tẹtisilẹ si adura si ihinyi.
41 Njẹ nisisiyi, dide, Oluwa Ọlọrun si ibi
isimi rẹ, iwọ ati apoti agbara rẹ ; jẹ ki a fi
igbala wọ̀ awọn alufa rẹ, Oluwa Ọlọrun, ki
o si jẹ ki awọn enia ayanfẹ rẹ ki o ma yọ̀
ninu ire.
42 Oluwa Ọlọrun, máṣe yi oju ẹni ororo
rẹ pada : ranti ãnu fun Dafidi, iranṣẹ rẹ.

## ORI 7.

BI Solomoni si ti pari adura igbà, iná bọ́
lati ọrun wà, o si jo ọrẹ sisun ati ẹbọ
na run ; ogo Oluwa si kún ile na.
2 Awọn alufa kò le wọ̀ inu ile Oluwa,
nitori ogo Oluwa kún ile Oluwa.
3 Gbogbo awọn ọmọ Israeli si ri bi iná
na ti bọ́ silẹ, ati ogo Oluwa sori ile na,
nwọn doju wọn bò ilẹ ti a fi okuta tẹ́,
nwọn si tẹriba, nwọn si yìn Oluwa, wipe,
Nitoriti o ṣeun ; nitoriti ãnu rẹ̀ duro lailai.
4 Ọba ati awọn enia si rubọ niwaju
Oluwa.
5 Solomoni ọba si rubọ ẹgbã-mọkanla
malu ati ọkẹ mẹfa agutan ; bẹ̃ni ọba, ati
gbogbo awọn enia yà ile Ọlọrun na si
mimọ́.

Digitized by Google

6 Awọn alufa duro lẹnu iṣẹ wọn; awọn
ọmọ Lefi pẹlu ohun-ọnà orin Oluwa, ti
Dafidi ọba ti ṣe lati yin Oluwa, nitori ti
ãnu rẹ̀ duro lailai, nigbati Dafidi nkọrin
iyin nipa ọwọ wọn; awọn alufa si fún ipè
niwaju wọn, gbogbo Israeli si dide duro.
7 Solomoni si yà arin agbala na si mimọ́
ti mbẹ niwaju ile Oluwa: nitori nibẹ li o
ru ẹbọ ọrẹ sisun, ati ọra ẹbọ alafia, nitori
pẹpẹ idẹ ti Solomoni ti ṣe kò le gbà ọrẹ
sisun, ati ọrẹ onjẹ ati ọ̀ra na.
8 Li akokò na pẹlu Solomoni se àse na
ni ijọ meje, ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀, ijọ
enia nlanla, lati iwọ Hamati titi de odò
Egipti.
9 Ati li ọjọ kẹjọ nwọn ṣe apejọ mimọ́;
nitori ti nwọn ṣe iyasi-mimọ́ pẹpẹ na li ọjọ
meje, ati àse na, ojo meje.
10 Ati li ọjọ kẹtalelogun oṣù keje, o rán
awọn enia pada lọ sinu agọ wọn, pẹlu ayọ̀
ati inudidùn nitori ore-ọfẹ ti Oluwa ti fi
hàn fun Dafidi, ati fun Solomoni, ati fun
Israeli, enia rẹ̀.
11 Solomoni si pari ile Oluwa, ati ile
ọba, ati gbogbo ohun ti o wá si ọkàn Solo-
moni lati ṣe ninu ile Oluwa, ati ninu ile
ontikararẹ̀, o si ṣe e jalẹ.
12 Oluwa si fi ara hàn Solomoni li oru,
o si wi fun u pe, Emi ti gbọ́ adura rẹ, emi
si ti yàn ihinyi fun ara mi, fun ile ẹbọ.
13 Bi mo ba sé ọrun ti kò ba si òjo, tabi
bi emi ba paṣẹ fun eṣú lati jẹ ilẹ na run,
tabi bi mo ba rán àjakalẹ-arun si ãrin awọn
enia mi;
14 Bi awọn enia mi ti a npè orukọ mi
mọ́, ba rẹ̀ ara wọn silẹ, ti nwọn ba si gba-
dura, ti nwọn ba si wá oju mi, ti nwọn ba
si yipada kuro ninu ọ̀na buburu wọn; ni-
gbana ni emi o gbọ́ lati ọrun wá, emi o si
dari ẹ̀ṣẹ wọn jì, emi o si wò ilẹ wọn sàn.
15 Nisisiyi oju mi yio ṣí, eti mi yio si tẹ́
si adura ibi yi.
16 Njẹ nisisiyi emi ti yàn, emi si ti yà
ile yi si mimọ́, ki orukọ mi ki o le ma wà
nibẹ lailai: ati oju mi ati ọkàn mi yio
ma wà nibẹ nigbagbogbo.
17 Ati iwọ, bi iwọ o ba rìn niwaju mi
bi Dafidi, baba rẹ ti rìn, ki o si ṣe gẹgẹ bi
gbogbo eyiti mo ti pa li aṣẹ fun ọ, bi iwọ o
ba si ṣe akiyesi aṣẹ mi ati idajọ mi;
18 Nigbana ni emi o fi idi itẹ ijọba rẹ
mulẹ, gẹgẹ bi emi ti ba Dafidi, baba rẹ dà
majẹmu, wipe, a kì yio fẹ ẹnikan kù fun ọ
ti yio ma ṣe akoso ni Israeli.
19 Ṣugbọn bi ẹnyin ba yipada, ti ẹ ba
si kọ̀ aṣẹ mi ati ofin mi silẹ, ti emi ti gbé
kalẹ niwaju nyin, ti ẹnyin ba si sìn ọlọrun
miran, ti ẹ si bọ wọn;
20 Nigbana ni emi o fà wọn tu tigbon-
gbo-ti-gbongbo kuro ni ilẹ ti emi ti fi fun
wọn; ati ile yi, ti emi ti yà si mimọ́ fun
orukọ mi, li emi o ta nù kuro niwaju mi,
emi o si sọ ọ di owe, ati ọ̀rọ-ẹgan larin
gbogbo orilẹ-ẹ̀de.
21 Ati ile yi, ti o ga, yio di ohun iyanu
fun gbogbo ẹni ti o gba ibẹ kọja; tobẹ̃ ti
yio si wipe, ẽṣe ti Oluwa fi ṣe bayi si ilẹ yi,
ati si ile yi?
22 A o si dahùn wipe, Nitori ti nwọn
kọ̀ Oluwa Ọlọrun awọn baba wọn silẹ, Ẹniti
o mu wọn ti ilẹ Egipti jade wá, ti nwọn si
di olọrun miran mu, ti nwọn si bọ wọn, ti
nwọn si sìn wọn: nitorina li o ṣe mu
gbogbo ibi yi ba wọn.

## ORI 8.

O SI ṣe lẹhin ogun ọdun ninu eyi ti So-
lomoni kọ́ ile Oluwa, ati ile ontika-
rarẹ̀.
2 Ni Solomoni kọ́ ilu wọnni ti Huramu
fi fun Solomoni, o si mu ki awọn ọmọ Isra-
eli ki o ma gbe ibẹ.
3 Solomoni si lọ si Hamati-Soba, o si
bori rẹ̀,
4 O si kọ́ Tadmori li aginju, ati gbogbo
ilu iṣura ti o kọ́ ni Hamati.
5 O kọ́ Bet-Horoni ti òke pẹlu, ati Bet-
Horoni ti isalẹ ilu odi, pẹlu ogiri, ilẹkun,
ati ọpa-idabu;
6 Ati Baalati, ati gbogbo ilu iṣura ti
Solomoni ni, ati gbogbo ilu kẹkẹ́, ati ilu
ẹlẹṣin, ati gbogbo eyiti Solomoni fẹ lati kọ́
ni Jerusalemu, ati ni Lebanoni ati ni gbo-
gbo ilẹ ijọba rẹ̀.
7 Gbogbo awọn enia ti o kù ninu awọn
ara Hitti, ati awọn Amori, ati awọn Pe-
resi, ati awọn Hifi ati awọn Jebusi, ti kì
iṣe ti inu ọmọ Israeli.
8 Ninu awọn ọmọ wọn, ti a kù silẹ
lẹhin wọn ni ilẹ na, ti awọn ọmọ Israeli kò
run kuro, awọn ni Solomoni bu iṣẹ-irú fun
titi o fi di oni yi.
9 Ṣugbọn ninu awọn ọmọ Israeli ni So-
lomoni kò fi ṣe ọmọ-ọ̀dọ fun iṣẹ rẹ̀; nitori
awọn li ọga-ogun ati olori awọn onikẹkẹ́
rẹ̀, ati awọn kẹkẹ́ rẹ̀, ati awọn ẹlẹṣin rẹ̀.
10 Awọn wọnyi li olori awọn alaṣẹ So-
lomoni ọba, adọtalerugba ti nṣakoso lori
awọn enia.
11 Solomoni si mu ọmọbirin Farao gòke
lati ilu Dafidi wá si ile ti o kọ́ fun u; ni-
tori ti o wipe, Ni temi, obirin kan ki yio

Digitized by Google

gbe inu ile Dafidi, ọba Israeli, nitori mimọ́
ni ibi ti apoti-ẹri Oluwa ti de.
12 Nigbana ni Solomoni ru ẹbọ ọre-sisun
si Oluwa lori pẹpẹ Oluwa, ti o ti tẹ niwaju
iloro na.
13 Ani nipa ilana ojojumọ, lati ma rubọ
gẹgẹ bi aṣẹ Mose, li ọjọjọ isimi, ati li oṣoṣu
titun, ati ajọ mimọ́, lẹrin mẹta li ọdun,
ani li ajọ aiwukara, li ajọ ọsẹ-meje, ati li
ajọ ipagọ.
14 O si yàn ipa awọn alufa, gẹgẹ bi
ilana Dafidi baba rẹ̀, si ìsin wọn, ati awọn
ọmọ Lefi si iṣẹ wọn, lati ma yìn, ati lati
ma ṣe iranṣẹ niwaju awọn alufa, bi ilana
ojojumọ: ati awọn adèna pẹlu ni ipa ti
wọn li olukuluku ẹnu-ọ̀na: nitori bẽni
Dafidi, enia Ọlọrun, ti pa a li aṣẹ.
15 Nwọn kò si yà kuro ninu ilana ọba
nipa ti awọn alufa, ati awọn ọmọ Lefi niti
olukuluku ọ̀ran, ati niti iṣura.
16 Gbogbo iṣẹ Solomoni li a ti pese silẹ
bayi de ọjọ ifi-ipilẹ ile Oluwa le ilẹ titi o
fi pari. A si pari ile Oluwa.
17 Nigbana ni Solomoni lọ si Esion-
Geberi, ati si Eloti, ati si eti okun ni ilẹ
Edomu.
18 Huramu si fi ọkọ̀ ranṣẹ si i, nipa
ọwọ awọn iranṣẹ rẹ̀, ati awọn iranṣẹ ti o
moye okun: nwọn si ba awọn iranṣẹ So-
lomoni lọ si Ofiri, lati ibẹ ni nwọn mu
ãdọta-le-ni-irinwo talenti wura wá, nwọn
si mu wọn tọ̀ Solomoni ọba wá.

## ORI 9.

NIGBATI ayaba Ṣeba gbọ́ òkiki Solo-
moni, o wá lati fi àlọ dán Solomoni
wò ni Jerusalemu, pẹlu ẹgbẹ́ nlanla, ati
ibakasiẹ ti o ru turari, ati wura li ọ̀pọlọpọ
ati okuta iyebiye; nigbati o si de ọdọ
Solomoni, o ba a sọ ohun gbogbo ti o wà
li ọkàn rẹ̀.
2 Solomoni si dahùn gbogbo ibère rẹ̀:
kò si si ohun kan ti o pamọ fun Solomoni
ti kò sọ fun u,
3 Nigbati ayaba Ṣeba si ti ri ọgbọ́n
Solomoni, ati ile ti o ti kọ́,
4 Ati onjẹ tabili rẹ̀, ati ijoko awọn
ọmọ-ọdọ rẹ̀, ati iduro awọn iranṣẹ rẹ̀, ati
aṣọ-wiwọ̀ wọn; ati awọn agbọti rẹ̀ pẹlu
aṣọ-wiwọ̀ wọn, ati àtẹgun ti o mba gòke
lọ si ile Oluwa; kò si kù agbara kan ninu
rẹ̀ mọ.
5 O si wi fun ọba pe, otitọ ni ọ̀rọ ti
mo gbọ́ ni ilẹ mi niti iṣe rẹ, ati ọgbọ́n rẹ:
6 Ṣugbọn emi kò gba ọ̀rọ wọn gbọ́, titi
mo fi de, ti oju mi si ti ri i; si kiyesi i,
a kò rò idaji titobi ọgbọ́n rẹ fun mi;
nitori ti iwọ kọja òkiki ti mo ti gbọ́.
7 Ibukún ni fun awọn enia rẹ, ibukún
si ni fun awọn iranṣẹ rẹ wọnyi, ti nduro
nigbagbogbo niwaju rẹ, ti o si ngbọ́ ọgbọ́n
rẹ.
8 Olubukún li Oluwa Ọlọrun rẹ, ti o
fẹran rẹ lati gbé ọ ka ori itẹ́ rẹ̀ lati ṣe
ọba fun Oluwa Ọlọrun rẹ: nitoriti Ọlọrun
rẹ fẹran Israeli lati fi idi wọn kalẹ lailai,
nitorina ni o ṣe fi ọ jọba lori wọn, lati ṣe
idajọ ati otitọ.
9 O si fun ọba li ọgọfa talenti wura, ati
turari lọpọlọpọ, ati okuta iyebiye: bẽni
kò ti isi iru turari gẹgẹ bi eyiti ayaba
Ṣeba fun Solomoni ọba.
10 Awọn iranṣẹ Huramu pẹlu, ati awọn
iranṣẹ Solomoni ti o mu wura Ofiri wá, si
mu igi-algumu, ati okuta iyebiye wá pẹlu.
11 Ọba si fi igi-algumu na ṣe àtẹgun ni
ile Oluwa, ati ni ile ọba, ati duru ati ohun
ọ̀na-orin fun awọn akọrin: a kò si ri iru
bẽ ri ni ilẹ Juda.
12 Solomoni ọba si fun ayaba Ṣeba li
ohun gbogbo ti o wù u, ohunkohun ti o
bère, li aika eyiti o mu wa fun ọba. Bẽni
o yipada, o si lọ si ilẹ rẹ̀, ati on ati awọn
iranṣẹ rẹ̀.
13 Njẹ nisisiyi iwọn wura ti o de fun
Solomoni li ọdun kan ni ọtalelẹgbẹta o
le mẹfa talenti wura.
14 Laika eyiti awọn oniṣowo ati awọn
èro mu wá. Ati awọn ọba Arabia, ati
awọn bãlẹ ilẹ na nmu wura ati fadakà tọ̀
Solomoni wá.
15 Solomoni ọba si ṣe igba asà wura
lilù: asà kan gba ẹgbẹta ṣekeli wura lilù.
16 Ọ̃dunrun apata wura lilù li o si ṣe;
apata kan gbà ọ̃dunrun ṣekeli wura: ọba
si fi wọn sinu ile igbo Lebanoni.
17 Ọba si ṣe itẹ́ ehin-erin nla kan, o si
fi wura daradara bò o.
18 Atẹgun mẹfa ni itẹ́ na ni, pẹlu apoti-
itisẹ wura kan, ti a dè mọ itẹ́ na, ati irọpa
ni iha mejeji ibi ijoko na, kiniun meji si
duro lẹba awọn irọpa na.
19 Kiniun mejila si duro lori atẹgun
mẹfẹfa na, ni iha ekini ati ni iha ekeji.
A kò ṣe iru rẹ̀ ri ni gbogbo ijọba.
20 Ati gbogbo ohun-elo mimu Solomoni
ọba jẹ wura, ati gbogbo ohun-elo ile igbo
Lebanoni, wura daradara ni: kò si ti
fadakà; a kò kà fadakà si nkankan li ọjọ
Solomoni.
21 Nitori awọn ọkọ̀ ọba nlọ si Tarṣiṣi
pẹlu awọn iranṣẹ Huramu; ẹ̃kan li ọdun

Digitized by Google

mẹta li awọn ọkọ̀ Tarṣiṣi ide, nwọn nmu
wura, ati fadakà, ati ehin-erin, ati inaki,
ati ẹiyẹ-ologe wá.
22 Solomoni ọba si tobi jù gbogbo ọba
aiye lọ li ọrọ̀ ati li ọgbón.
23 Gbogbo awọn ọba aiye si nwá oju
Solomoni, lati gbọ́ ọgbọ́n rẹ̀ ti Ọlọrun ti
fi si i li ọkàn.
24 Olukuluku si mu ọrẹ tirẹ̀ wá, ohun-
elo fadakà ati ohun-elo wura, ati aṣọ ibora,
ihamọra, ati turari, ẹṣin, ati ibaka, iye
kan li ọdọdun.
25 Solomoni si ni ẹgbaji ile fun ẹṣin ati
kẹkẹ́, ati egbafa ẹlẹṣin, ti o fi si awọn ilu
kẹkẹ́, ati ọdọ ọba ni Jerusalemu.
26 O si jọba lori gbogbo awọn ọba lati
odò (Ferate) titi de ilẹ awọn ara Filistia
ati de àgbegbe Egipti.
27 Ọba si sọ fadakà dabi okuta ni Jeru-
salemu, ati igi-kedari li o si ṣe bi sikamore,
ti o wà ni pẹtẹlẹ li ọpọlọpọ.
28 Nwọn si mu ẹṣin tọ̀ Solomoni lati
Egipti wá, ati lati ilẹ gbogbo.
29 Ati iyokù iṣe Solomoni ti iṣaju ati
ti ikẹhin, a kò ha kọ wọn sinu iwe Natani
woli, ati sinu asọtẹlẹ Ahijah, ara Ṣilo,
ati sinu iran Iddo, ariran, sipa Jeroboamu,
ọmọ Nebati.
30 Solomoni si jọba ni Jerusalemu lori
gbogbo Israeli li ogoji ọdun.
31 Solomoni si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀.
a si sìn i ni ilu Dafidi baba rẹ̀: Reho-
boamu, ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 10.

REHOBOAMU si lọ si Ṣekemu: nitori
gbogbo Israeli wá si Ṣekemu lati fi
i jẹ ọba.
2 O si ṣe, nigbati Jeroboamu, ọmọ Ne-
bati gbọ́, on si wà ni Egipti nibiti o ti
salọ kuro niwaju Solomoni ọba, ni Jero-
boamu pada ti Egipti wá.
3 Nwọn si ranṣẹ pè e. Bẽni Jeroboamu
ati gbogbo Israeli wá, nwọn si ba Reho-
boamu sọ̀rọ, wipe.
4 Baba rẹ mu ki àjaga wa ki o wuwo:
njẹ nisisiyi iwọ ṣẹkù kuro ninu ìsin baba
rẹ ti o nira, ati àjaga wuwo rẹ̀ ti o fi bọ̀
wa lọrùn, awa o si ma sìn ọ.
5 On si wi fun wọn pe, Ẹ tun pada
tọ̀ mi wá lẹhin ijọ mẹta. Awọn enia na
si lọ.
6 Rehoboamu ọba si ba awọn àgbagba
ti o ti nduro niwaju Solomoni baba rẹ̀;
nigbati o wà lãye dá imọran, wipe, Imọran
kili ẹnyin dá lati da awọn enia yi lohùn?
7 Nwọn si ba a sọ̀rọ pe, bi iwọ ba ṣe
ire fun enia yi, ti iwọ ba ṣe ohun ti o
wù wọn, ti o ba si sọ̀rọ rere fun wọn, nwọn
o ma ṣe iranṣẹ rẹ nigbagbogbo.
8 Ṣugbọn o kọ̀ imọran awọn àgbagba ti
nwọn ba a dá, o si ba awọn ipẹrẹ ti o
dàgba pẹlu rẹ̀ damọran, ti o duro niwaju rẹ̀.
9 On si wi fun wọn pe, Imọran kili
ẹnyin dá, ki awa ki o le da awọn enia yi
lohùn, ti o ba mi sọ̀rọ, wipe, Ṣe ki àjara
ti baba rẹ fi bọ̀ wa lọrùn ki o fuyẹ diẹ?
10 Awọn ipẹrẹ ti a tọ́ pẹlu rẹ̀ si sọ fun
u wipe, Bayi ni iwọ o da awọn enia na
li ohùn ti o sọ fun ọ, wipe, Baba rẹ mu
àjaga wa di wuwo, ṣugbọn iwọ ṣe e ki o
fẹrẹ diẹ fun wa; bayi ni ki iwọ ki o wi
fun wọn, Ọmọdirin mi yio nipọn jù ẹgbẹ́
baba mi lọ.
11 Njẹ nisisiyi baba mi ti fi àjaga wuwo
bọ̀ nyin lọrùn, emi o si fi kún àjaga nyin:
baba mi fi paṣan nà nyin, ṣugbọn akẽke li
emi o fi nà nyin.
12 Jeroboamu ati gbogbo awọn enia si
tọ̀ Rehoboamu wá ni ijọ kẹta gẹgẹ bi ọba
ti dá, wipe, Ẹ pada tọ̀ mi wá ni ijọ kẹta.
13 Nigbana ni ọba da wọn li ohùn
akọ; Rehoboamu ọba si kọ̀ imọran awọn
àgbagba silẹ.
14 O si da wọn li ohùn gẹgẹ bi imọran
awọn ipẹrẹ, wipe, Baba mi mu àjaga nyin
ki o wuwo, ṣugbọn emi o fi kún u; baba
mi ti fi paṣan nà nyin, ṣugbọn emi o fi
akẽke nà nyin.
15 Bẽni ọba kò si fetisi ti awọn enia
na: nitori ṣiṣe ọ̀ran na lati ọwọ Ọlọrun
wá ni, ki Oluwa ki o le mu ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ, ti
o sọ nipasẹ Ahijah, ara Ṣilo fun Jeroboamu,
ọmọ Nebati.
16 Nigbati gbogbo Israeli ri pe, ọba
kọ̀ lati fetisi ti wọn, awọn enia na da ọba
lohùn, wipe, Ipin kili a ni ninu Dafidi?
awa kò si ni ini kan ninu ọmọ Jesse:
Israeli, olukuluku sinu agọ rẹ̀: nisisiyi
Dafidi, mã bojuto ile rẹ. Bẽni gbogbo
Israeli lọ sinu agọ wọn,
17 Ṣugbọn awọn ọmọ Israeli ti ngbe ilu
Juda wọnni, Rehoboamu jọba lori wọn.
18 Nigbana ni Rehoboamu ọba ran Ha-
doramu ti iṣe olori iṣẹ-irú; awọn ọmọ
Israeli si sọ ọ li okuta, o si kú. Ṣugbọn
Rehoboamu ọba yara lati gun kẹkẹ́ rẹ̀ lati
salọ si Jerusalemu.
19 Bẽni Israeli si ya kuro lọdọ ilẹ Dafidi
titi o fi di oni yi.

Digitized by Google

## ORI 11.

ƷATI Rehoboamu si de Jerusalemu,
kó ile Juda ati Benjamini jọ, ọkẹ
enia ti a yàn, ti nwọn iṣe ologun,
Israeli jà, ki o le mu ijọba na pada
ọ Rehoboamu.
ugbọn ọ̀rọ Oluwa tọ Ṣemaiah, enia
ı, wá, wipe,
ọ fun Rehoboamu ọmọ Solomoni, ọba
ati fun gbogbo Israeli ni Juda ati
mini, wipe,
ayi li Oluwa wi, ẹnyin kò gbọdọ
.ọ, bẽli ẹnyin kò gbọdọ ba awọn ara-
ı nyin jà: ki olukuluku pada si ile
ıitori ọ̀ran yi lati ọdọ mi wá ni.
si gbà ọ̀rọ Oluwa gbọ́, nwọn si
a kuro lati lọ iba Jeroboamu.
ʿehoboamu si ngbe Jerusalemu, o si
. olodi ni Juda.
) kọ́ Betlehemu pẹlu, ati Etamu, ati
',
ıti Bet-Suri, ati Soko, ati Adullamu,
ıti Gati, ati Mareṣa, ati Sifu,
ıti Adoraimu, ati Lakiṣi, ati Aseki,
Ati Sora, ati Aijaloni, ati Hebroni,
'à ni Juda ati ni Benjamini, awọn ilu

O si mu awọn ilu olodi lagbara, o si
ọn balogun sinu wọn ati akojọ onjẹ,
'oro ati ọti-waini.
Ati ni olukuluku ilu li o fi asà ati
i, o si mu wọn lagbara gidigidi, o si
da ati Benjamini labẹ rẹ̀.
Ati awọn alufa ati awọn ọmọ Lefi, ti
ni gbogbo Israeli, tọ̀ ọ lọ lati gbogbo
)e wọn wá.
Nitori ti awọn ọmọ Lefi fi igberiko
silẹ, ati ini wọn, nwọn si lọ si Juda
ɜrusalemu: nitori Jeroboamu ati awọn
rẹ̀ ti le wọn kuro lati má ṣiṣẹ alufa fun
'a.
O si yàn awọn alufa fun ibi-giga
ıi, ati fun awọn ere-obukọ ati fun
rọ-malu ti o ti ṣe.
Lẹhin wọn iru awọn ti o fi ọkàn wọn
i wá Oluwa Ọlọrun Israeli lati inu
bo awọn ẹ̀ya Israeli wá, si wá si Jeru-
nu, lati ṣe irubọ si Oluwa Ọlọrun awọn
wọn.
Bẽni nwọn si mu ijọba Juda lagbara,
ı mu ki Rehoboamu, ọmọ Solomoni
lagbara li ọdun mẹta: nitori li ọdun
ι ni nwọn rin li ọ̀na Dafidi ati Solo-
i.
ǀ Rehoboamu si mu Mahalati, ọmọ-
birin Jerimoti, ọmọ Dafidi, li aya, ati
Abihaili, ọmọbirin Eliabi, ọmọ Jesse:
19 Ẹniti o bi ọmọkọnrin wọnyi fun u;
Jeuṣi, ati Ṣamariah, ati Sahamu.
20 Ati lẹhin rẹ̀, o mu Maaka, ọmọbirin
Absalomu ti o bi Abijah fun u, ati Attai,
ati Sisa, ati Ṣelomiti.
21 Rehoboamu si fẹran Maaka ọmọbirin
Absalomu, jù gbogbo awọn aya rẹ̀ ati àle
rẹ̀ lọ: (nitoriti o ni aya mejidilogun, ati
ọgọta àle: o si bi ọmọkọnrin mejidilọgbọn
ati ọgọta ọmọbirin).
22 Rehoboamu si ṣe Abijah, ọmọ Maaka,
li olori lati ṣe olori ninu awọn arakọnrin
rẹ̀: nitori ti o rò lati fi i jọba.
23 On si huwà ọlọgbọ́n, o si tú ninu
gbogbo awọn ọmọ rẹ̀ ka si gbogbo ilẹ Juda
ati Benjamini, si olukuluku ilu olodi: o si
fun wọn li onjẹ li ọ̀pọlọpọ. O si fẹran ọ̀pọ-
lọpọ obirin.

## ORI 12.

O SI ṣe, nigbati Rehoboamu ti fi idi ijọba
rẹ̀ mulẹ ti o si ti mu ara rẹ̀ le, o kọ̀
ofin Oluwa silẹ, ati gbogbo Israeli pẹlu rẹ̀.
2 O si ṣe li ọdun karun Rehoboamu ọba,
ni Ṣiṣaki, ọba Egipti, gòke wá si Jerusale-
mu, nitoriti nwọn ti dẹṣẹ si Oluwa.
3 Pẹlu ẹgbẹfa kẹkẹ́, ati ọkẹ mẹta ẹlẹṣin:
awọn enia ti o ba a ti Egipti wá kò niye;
awọn ara Libia, awọn ara Sukki, ati awọn
ara Etiopia.
4 O si kó awọn ilu olodi ti iṣe ti Juda, o
si wá si Jerusalemu.
5 Nigbana ni Ṣemaiah, woli, tọ̀ Rehobo-
amu wá, ati awọn ijoye Juda, ti o kojọ pọ̀
si Jerusalemu nitori Ṣiṣaki, o si wi fun wọn
pe, Bayi li Oluwa wi, enyin ti kọ̀ mi silẹ,
nitorina li emi si ṣe fi nyin silẹ si ọwọ
Ṣiṣaki.
6 Nigbana li awọn ijoye Israeli ati ọba
rẹ̀ ara wọn silẹ; nwọn si wipe: Oluwa li
olododo!
7 Nigbati Oluwa ri pe nwọn rẹ̀ ara wọn
silẹ, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Ṣemaiah wá, wipe,
Nwọn ti rẹ̀ ara wọn silẹ; nitorina emi kì
o run wọn, ṣugbọn emi o fun wọn ni
igbala diẹ: a kì yio dà ibinu mi sori Jeru-
salemu nipa ọwọ Ṣiṣaki.
8 Ṣugbọn nwọn o ma ṣe iranṣẹ rẹ̀: ki
nwọn ki o le mọ̀ isin mi, ati isin ijọba ilẹ
wọnni.
9 Bẽni Ṣiṣaki, ọba Egipti, goke wá si
Jerusalemu, o si kó iṣura ile Oluwa lọ, ati
iṣura ile ọba; o kó gbogbo rẹ̀: o kó awọn
asà wura lọ pẹlu ti Solomoni ti ṣe.

Digitized by Google

10 Rehoboamu ọba si ṣe asà idẹ ni ipò wọn, o si fi wọn le ọwọ olori ẹṣọ ti ntọju ọ̀na ile ọba.

11 O si ṣe, nigbakugba ti ọba ba si wọ̀ ile Oluwa lọ, awọn ẹṣọ a de, nwọn a si kó wọn wá, nwọn a si kó wọn pada sinu iyara ẹṣọ.

12 Nigbati o si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, ibinu Oluwa yipada kuro lọdọ rẹ̀, ti kò fi run u patapata: ni Juda pẹlu, ohun rere si mbẹ.

13 Bẹ̃ni Rehoboamu ọba mu ara rẹ̀ le ni Jerusalemu, o si jọba: nitori Rehoboamu jẹ ẹni ọdun mọkanlelogun nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba li ọdun mẹtalelogun ni Jerusalemu, ilu ti Oluwa ti yàn lati inu gbogbo eya Israeli, lati fi orukọ rẹ̀ sibẹ. Orukọ iya rẹ̀ si ni Naama, ara Ammoni.

14 O si ṣe buburu, nitori ti kò mura ọkàn rẹ̀ lati wá Oluwa.

15 Njẹ iṣe Rehoboamu, ti iṣaju ati ti ikẹhin, a kò ha kọ wọn sinu iwe Ṣemaiah woli, ati ti Iddo, ariran, nipa iwe itan idile? Ọtẹ si wà lãrin Rehoboamu ati Jeroboamu nigbagbogbo.

16 Rehoboamu si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, a si sìn i ni ilu Dafidi: Abijah ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 13.

LI ọdun kejidilogun Jeroboamu, ọba, ni Abijah bẹ̀rẹ si ijọba lori Juda.

2 O jọba li ọdun mẹta ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ si ni Mikaiah ọmọbirin Urieli ti Gibea, Ọtẹ si wà lãrin Abijah ati Jeroboamu.

3 Abijah si fi awọn alagbara akọni ologun dì ogun na, ani ogún ọkẹ enia ti a yàn, Jeroboamu pẹlu si fi ogoji ọkẹ enia ti a yàn, awọn alagbara akọni enia tẹ̀ ogun si i.

4 Abijah si duro lori oke Semaraimu, ti o wà li òke Efraimu, o si wipe, Ẹ gbọ́ temi, Jeroboamu ati gbogbo Israeli!

5 Kò ha tọ́ ki ẹnyin ki o mọ̀ pe: Oluwa Ọlọrun Israeli fi ijọba lori Israeli fun Dafidi lailai, ani fun u, ati fun awọn ọmọ rẹ̀ nipa majẹmu iyọ̀?

6 Jeroboamu, ọmọ Nebati, iranṣẹ Solomoni, ọmọ Dafidi dide, o si ṣọ̀tẹ si oluwa rẹ̀.

7 Awọn enia lasan si ko ara wọn jọ si ọdọ rẹ̀, awọn ọmọ ẹni buburu, nwọn si mu ara wọn le si Rehoboamu, ọmọ Solomoni, nigbati Rehoboamu wà li ọdọmọde ti inu rẹ̀ si rọ̀, ti kò si le kò wọn loju.

8 Ati nisisiyi ẹnyin rò lati kò ijọba Oluwa loju li ọwọ ọmọ Dafidi; ọ̀pọlọpọ si li ẹnyin, ati pẹlu nyin awọn ẹgbọrọmalu wura ti Jeroboamu ṣe li ọlọrun fun nyin.

9 Ẹnyin kò ha ti lé awọn alufa Oluwa jade, awọn ọmọ Aaroni, ati awọn ọmọ Lefi, ẹnyin si ti ṣe awọn alufa fun ara nyin, gẹgẹ bi iṣe awọn orilẹ-ède ilẹ miran? bẹ̃ni ẹnikẹni ti o ba wá, ti ọwọ rẹ kún pẹlu ọdọakọ-malu ati àgbo meje, on na le ma ṣe alufa awọn ti kì iṣe ọlọrun.

10 Ṣugbọn bi o ṣe ti wa ni, Oluwa li Ọlọrun wa, awa kò si kọ̀ ọ silẹ ati awọn alufa, ti nṣe iranṣẹ fun Oluwa, ani awọn ọmọ Aaroni ati awọn ọmọ Lefi ninu iṣẹ wọn.

11 Nwọn si nsun ọrẹ-ẹbọ sisun ati turari didùn li orowurọ ati li alalẹ si Oluwa: àkara ifihàn pẹlu ni nwọn si nto lori tabili mimọ́; ati ọpa fitila wura pẹlu fitila wọn, lati ma jó lalalẹ; nitori ti awa npa aṣẹ Oluwa Ọlọrun wa mọ́; ṣugbọn ẹnyin kọ̀ ọ silẹ.

12 Si kiyesi i, Ọlọrun tikararẹ̀ si wà pẹlu wa li Olori wa, ati awọn alufa rẹ̀ pẹlu ipè didún ijaiya lati dún si nyin, Ẹnyin ọmọ Israeli, ẹ máṣe ba Oluwa Ọlọrun awọn baba nyin jà; nitori ẹ kì yio ṣe rere.

13 Ṣugbọn Jeroboamu mu ki ogun-ẹ̀hin ki o bú wọn li ẹhin: bẹ̃ni nwọn mbẹ niwaju Juda, ati ogun-ẹhin na si mbẹ lẹhin wọn.

14 Nigbati Juda si bojuwo ẹhin, si kiyesi i, ogun mbẹ niwaju ati lẹhin: nwọn si ke pè Oluwa, awọn alufa si fun ipè.

15 Olukuluku, ọkọnrin Juda si hó: o si ṣe, bi awọn ọkọnrin Juda si ti hó, ni Ọlọrun kọlu Jeroboamu ati gbogbo Israeli niwaju Abijah ati Juda.

16 Awọn ọmọ Israeli si sa niwaju Juda: Ọlọrun si fi wọn le wọn lọwọ.

17 Abijah ati awọn ẹnia rẹ̀ si pa ninu wọn li ọ̀pọlọpọ: bẹ̃ni ọkẹ mẹdọgbọn ọkọnrin ti a yàn ṣubu ni pipa ninu Israeli.

18 Bayi li a rẹ̀ awọn ọmọ Israeli silẹ li akoko na, awọn ọmọ Juda si bori, nitori ti nwọn gbẹkẹle Oluwa Ọlọrun awọn baba wọn.

19 Abijah si lepa Jeroboamu, o si gbà ilu lọwọ rẹ̀, Beteli pẹlu awọn ilu rẹ̀, ati Jeṣana pẹlu awọn ilu rẹ̀, ati Efraimu pẹlu awọn ilu rẹ̀.

20 Bẹ̃ni Jeroboamu kò si tun li agbara mọ li ọjọ Abijah: Oluwa si lù u, o si kú.

21 Abijah si di alagbara, o si gbe obirin mẹtala ni iyawo, o si bi ọmọkọnrin mejilelogun, ati ọmọbirin mẹrindilogun.

22 Ati iyokù iṣe Abijah, ati iwà rẹ̀, ati iṣẹ rẹ̀, a kọ wọn sinu iwe-itumọ Iddo, woli.

Digitized by Google

Bẽli Abijah sùn pẹlu awọn baba rẹ̀,
si sìn i ni ilu Dafidi: Asa ọmọ rẹ̀ si
i ipò rẹ̀. Li ọjọ rẹ̀, ilẹ na wà li ala-
ọdun mẹwa.

## ORI 14.

. si ṣe eyi ti o dara, ti o si tọ́ li oju
Ọluwa Ọlọrun rẹ̀.
Nitori ti o mu pẹpẹ awọn ajeji oriṣa
ati ibi giga wọnni, o si wó awọn ere
o si bẹ́ ere-oriṣa wọn lulẹ:
) si paṣẹ fun Juda lati ma wá Oluwa
ın awọn baba wọn, ati lati ma pa aṣẹ
ìn rẹ mọ́.
) si mu ibi giga wọnni ati ọwọ̀n-õrun
ıi kuro lati inu gbogbo ilu Juda: ijọ-
ı si wà li alafia niwaju rẹ̀.
O si kọ́ ilu olodi wọnni ni Juda, nito-
ilẹ na ni isimi, on kò si ni ogun li
. wọnni; nitori Oluwa ti fun wọn ni
.
O si sọ fun Juda pe, Ẹ jẹ ki a kọ́ ilu
ıi, ki a si mọdi yi wọn ka, ati ile-iṣọ,
ın ati ọpa-idabu, nigbati ilẹ na si wà
ju wa, nitori ti awa ti wá Oluwa Ọlọ-
wa, awa ti wá a, on si ti fun wa ni
i yikakiri. Bẽni nwon kọ́ wọn, nwọn
rere.
Asa si ni ogun ti ngbé asà ati ọ̀kọ, ọkẹ
ogun lati inu Juda wá, ati lati inu
jamini wá, ọkẹ mẹrinla ti ngbé apata
ti nfa ọrun: gbogbo wọnyi si ni akọni
n.
Sera, ara Etiopia, si jade si wọn, pẹlu
ta ọkẹ enia, ati õdunrun kẹkẹ́; nwọn
si Mareṣa.
Asa si jade tọ̀ ọ, nwọn si tẹ ogun li
ıifoji Sefata lẹba Mareṣa.
0 Asa si ke pe Oluwa Ọlọrun rẹ̀, o si
ıe, Oluwa! lọdọ rẹ bakanna ni fun ọ
. ràn alagbara enia lọwọ, tabi ẹniti kò li
ara: ràn wa lọwọ, Oluwa Ọlọrun wa;
ori ti awa gbẹkẹ le ọ, li orukọ rẹ li awa
ọ̀pọlọpọ yi lọ, Oluwa, iwọ li Ọlọrun
; máṣe jẹ ki enia ki o bori rẹ,
11 Bẽli Oluwa kọlù awọn ara Etiopia
vaju Asa, ati niwaju Juda: awọn ara
iopia si sa.
12 Ati Asa ati awọn enia ti o wà lọdọ
lepa wọn de Gerari: a si bi awọn ara
iopia ṣubu ti ẹnikan kò tun wà li ãye;
ori ti a ṣẹ́ wọn niwaju Oluwa ati niwaju
un rẹ̀; nwọn si kó ọ̀pọlọpọ ikogun lọ.
13 Nwọn si kọlu gbogbo ilu yikakiri
rari: nitori ti ẹ̀ru Oluwa bà wọn, nwọn
si kó gbogbo ilu na, nitori ikógun pọ̀ rekọ-
ja ninu wọn.
14 Nwọn si kọlù awọn agbo-ẹran-ọsin,
nwọn si kò ọ̀pọlọpọ agutan ati ibakasiẹ lọ,
nwọn si pada wá si Jerusalemu.

## ORI 15.

EMI Ọlọrun si wá si ara Asariah, ọmọ
Odedi:
2 O si jade lọ ipade Asa, o si wi fun u
pe, Ẹ gbọ́ tẹmi, Asa, ati gbogbo Juda ati
Benjamini! Oluwa pẹlu nyin, nitori ti
ẹnyin ti wà pẹlu rẹ̀; bi ẹnyin ba si ṣafẹri
rẹ̀, ẹnyin o ri i; ṣugbọn bi ẹnyin ba kọ̀ ọ,
on o si kọ̀ nyin.
3 Njẹ ọjọ pupọ ni Israeli ti wà laisìn
Ọlọrun otitọ, ati laini alufa ti nkọni, ati
laini ofin.
4 Ṣugbọn nwọn yipada si Oluwa, Ọlọ-
run Israeli, ninu wahala wọn, nwọn si ṣe
awari rẹ̀, nwọn si ri i.
5 Ati li ọjọ wọnni alafia kò si fun ẹniti
o njade, tabi fun ẹniti nwọle, ṣugbọn iba-
nujẹ pupọ li o wà lori gbogbo awọn olugbe
ilẹ wọnni.
6 Orilẹ-èdè si kọlù orilẹ-ède, ati ilu si
ilu: nitori ti Ọlọrun fi oniruru ipọnju bà
wọn ninu jẹ.
7 Ṣugbọn ẹnyin mu ara le, ki ẹ má si dẹ
ọwọ nyin: nitori iṣẹ nyin yio ni ère.
8 Nigbati Asa gbọ́ ọ̀rọ wọnyi, ati asọtẹlẹ
Odedi woli, o mu ara le, o si mu awọn
ohun irira kuro lati inu gbogbo ilẹ Juda
ati Benjamini, ati lati inu ilu ti o ti gbà
lati oke Efraimu, o si tun pẹpẹ Oluwa ṣe,
ti o wà niwaju iloro Oluwa.
9 O si kó gbogbo Juda ati Benjamini jọ,
ati awọn alejo ti o pẹlu wọn lati inu Efrai-
mu ati Manasse, ati lati inu Simeoni wá:
nitori ti nwọn ya li ọ̀pọ̀'ọpọ sọdọ rẹ̀ lati inu
Israeli wá, nigbati nwọn ri pe, Oluwa
Ọlọrun rẹ̀ wà pẹlu rẹ̀.
10 Bẽni nwọn kò ara wọn jọ si Jerusa-
lemu, li oṣù kẹta, li ọdun kẹdogun ijọba
Asa.
11 Nwọn si fi ninu ikógun ti nwọn kó
wá, rubọ si Oluwa li ọjọ na, ọdẹgbãrin
akọ-malu ati ọdẹgbãrin agutan.
12 Nwọn si tun dá majẹmu lati wá
Oluwa Ọlọrun awọn baba wọn, tinutinu
wọn ati tọkàntọkàn wọn.
13 Pe, ẹnikẹni ti kò ba wá Oluwa Ọlọ-
run Israeli, pipa li a o pa a, lati ẹni-kekere
de ẹni-nla, ati ọkọnrin ati obirin.
14 Nwọn si fi ohùn rara bura fun Oluwa,
ati pẹlu ariwo, ati pẹlu ipè ati pẹlu fère.

Digitized by Google

15 Gbogbo Juda si yọ̀ si ibura na: nitoriti nwọn fi tinu-tinu wọn bura, nwọn si fi gbogbo ifẹ inu wọn wá a; nwọn si ri i: Oluwa si fun wọn ni isimi yikakiri.
16 Pẹlupẹlu Maaka, iya Asa, li ọba mu u kuro lati má ṣe ayaba, nitoriti o yá ere fun oriṣa rẹ̀: Asa si ké ere rẹ̀ lulẹ, o si tẹ̀ ẹ mọlẹ, o si sun u nibi odò Kidroni.
17 Ṣugbọn a kò mu ibi giga wọnni kuro ni Israeli: kiki ọkàn Asa wà ni pipé li ọjọ rẹ̀ gbogbo.
18 O si mu ohun mimọ́ wọnni ti baba rẹ̀, ati ohun mimọ́ wọnni ti on tikararẹ̀ wá sinu ile Ọlọrun, fadakà, wura, ati ohun-elo wọnni.
19 Ogun kò si mọ titi di ọdun karundilogoji ọba Asa.

## ORI 16.

LI ọdun kẹrindilogoji ijọba Asa, Baaṣa, ọba Israeli, gòke wá si Juda, o si kọ́ Rama, nitori ki o má ba jẹ ki ẹnikan ki o jade, tabi ki o wọle tọ̀ Asa, ọba Juda lọ.
2 Nigbana ni Asa mu fadakà ati wura jade lati inu iṣura ile Oluwa wá, ati ile ọba, o si ranṣẹ si Benhadadi, ọba Siria, ti ngbe Damasku, wipe,
3 Majẹmu kan wà larin temi tirẹ, bi o ti wà lãrin baba mi ati baba rẹ; kiyesi i, mo fi fadakà ati wura ranṣẹ si ọ; lọ, bà majẹmu ti o ba Baaṣa, ọba Israeli dá jẹ, ki o le lọ kuro lọdọ mi.
4 Benhadadi si gbọ́ ti Asa ọba, o si rán awọn olori ogun rẹ̀ si ilu Israeli wọnni, nwọn si kọlù Ijoni, ati Dani, ati Abel-Maimu, ati gbogbo ilu iṣura Naftali.
5 O si ṣe, nigbati Baaṣa gbọ́, o ṣiwọ ati-kọ́ Rama, o si dá iṣẹ rẹ̀ duro.
6 Ṣugbọn Asa ọba kó gbogbo Juda jọ; nwọn si kó okuta ati igi Rama lọ, eyiti Baaṣa nfi kọ́le; o si fi kọ́ Geba ati Mispa.
7 Li àkoko na Hanani, ariran, wá sọdọ Asa, ọba Juda, o si wi fun u pe, Nitoriti iwọ gbẹkẹle ọba Siria, iwọ kò si gbẹkẹle Oluwa Ọlọrun rẹ, nitorina ni ogun ọba Siria ṣe bọ́ lọwọ rẹ.
8 Awọn ara Etiopia ati awọn ara Libia kì iha iṣe ogun nla, pẹlu ọ̀pọlọpọ kẹkẹ́ ati ẹlẹṣin? ṣugbọn nitoriti iwọ gbẹkele Oluwa, on fi wọn le ọ lọwọ.
9 Nitoriti oju Oluwa nlọ siwa sẹhin ni gbogbo aiye, lati fi agbara fun awọn ẹni ọlọkàn pipe si ọdọ rẹ̀. Ninu eyi ni iwọ hùwa aṣiwere: nitorina lati isisiyi lọ ogun yio ma ba ọ jà.
10 Asa si binu si ariran na, o si fi i sinu tubu; nitoriti o binu si i niti eyi na. Asa si ni ninu awọn enia na lara li akokò na.
11 Si kiyesi i, iṣe Asa ti iṣaju ati ti ikẹhin, wò o, a kọ wọn sinu iwe awọn ọba Juda ati Israeli.
12 Ati li ọdun kọkandilogoji ijọba rẹ̀, Asa ṣe aisan li ẹsẹ rẹ̀, titi àrun rẹ̀ fi pọ̀ gidigidi: sibẹ ninu aisan rẹ̀ on kò wá Oluwa, bikòṣe awọn oniṣegun.
13 Asa si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, o si kú li ọdun kọkanlelogoji ijọba rẹ̀.
14 Nwọn si sin i sinu isa-okú, ti o gbẹ́ fun ara rẹ̀ ni ilu Dafidi, nwọn si tẹ́ ẹ lori àkete ti a fi õrun-didùn kùn, ati oniruru turari ti a fi ọgbọ́n awọn alapolu pèse: nwọn si ṣe ijona nlanla fun u.

## ORI 17.

JEHOṢAFATI, ọmọ rẹ̀ si joba ni ipò rẹ̀, o si mu ara rẹ̀ le si Israeli.
2 O si fi ogun sinu gbogbo ilu olodi Juda, o si fi ẹgbẹ-ogun si ilẹ Juda ati sinu ilu Efraimu wọnni, ti Asa baba rẹ̀ ti gbà.
3 Oluwa si wà pẹlu Jehoṣafati, nitoriti o rìn ninu ọ̀na iṣaju Dafidi, baba rẹ̀, kò si wá Baalimu:
4 Ṣugbọn o wá Ọlọrun baba rẹ̀, o si rìn ninu ofin rẹ̀, ki iṣe bi iṣe Israeli.
5 Nitorina ni Oluwa fi idi ijọba na mulẹ li ọwọ rẹ̀; gbogbo Juda si ta Jehoṣafati li ọrẹ, on si li ọrọ̀ ati ọlá li ọ̀pọlọpọ.
6 Ọkàn rẹ̀ si gbé soke li ọ̀na Oluwa: pẹlupẹlu o si mu ibi giga wọnni ati ere-oriṣa kuro ni Juda.
7 Ati li ọdun kẹta ijọba rẹ̀, o ranṣẹ si awọn ijoye rẹ̀, ani si Benhaili ati si Obadiah ati Sekariah, ati si Netaneeli, ati si Mikaiah, lati ma kọ́ni ninu ilu Juda wọnni.
8 Ati pẹlu wọn, o rán awọn ọmọ Lefi, ani Ṣemaiah, ati Netaniah, ati Sebadiah, ati Asaheli, ati Ṣemiramotu, ati Jehonatani, ati Adonijah, ati Tobijah, ati Tob-Adonijah, awọn ọmọ Lefi; ati pẹlu wọn Eliṣama, ati Jehoramu, awọn alufa.
9 Nwọn si kọ́ni ni Juda, nwọn si ni ofin Oluwa pẹlu wọn, nwọn si lọ kakiri ja gbogbo ilu Juda, nwọn si kọ́ awọn enia.
10 Ẹru Oluwa si ba gbogbo ijọba ilẹ na, ti o wà yikakiri Juda, tobẹ̃ ti nwọn kò ba Jehoṣafati jagun kan.
11 Ati ninu awọn ara Filistia mu ọrẹ fun Jehoṣafati wá ati fadakà owo ọba: awọn ara Arabia si mu ọwọ́-ẹran fun u wá, ẹgbãrin àgbo o di ọ̃dunrun, ati ẹgbãrin obukọ di ọ̃dunrun.

Digitized by Google

Jehoṣafati si npọ̀ si i gidigidi: o si
olodi, ati ilu iṣura ni Juda.
O si ni iṣura pupọ ni ilu Juda; ati
jagunjagun, awọn alagbara akọni
in ti o wà ni Jerusalemu.
Wọnyi ni iye wọn gẹgẹ bi ile baba
Ninu Juda, awọn olori ẹgbẹgbẹrun;
, olori, ati pẹlu rẹ̀, ọkẹ mẹ̃dogun
ara akọni ọkọnrin.
Ati atẹle rẹ̀ ni Jehohanani olori, ati
rẹ̀ ọkẹ mẹrinla ọkọnrin.
Ati atẹle rẹ̀ ni Amasiah, ọmọ Sikri,
fi tinutinu fi ara rẹ̀ fun Oluwa; ati
rẹ̀ ọkẹ mẹwa alagbara akọni ọkọnrin.
Ati ninu Benjamini; Eliada alagbara
i ọkọnrin, ati pẹlu rẹ̀ awọn enia ti nfi
ati apata hamọra, ọkẹ mẹwa.
Ati atẹle rẹ̀ ni Jehosabadi, ati pẹlu
ẹ mẹsan, ti o mura silẹ de ogun.
Wọnyi nduro tì ọba, li aika awọn ti
i sinu ilu olodi ni gbogbo Juda.

## ORI 18.

IOṢAFATI si li ọrọ̀ ati ọlá li ọ̀pọlọpọ,
ɔ si ba Ahabu dá ana.
Lẹhin ọdun melokan, on sọ̀kalẹ tọ
ɔu lọ si Samaria. Ahabu si pa agutan
ıalu fun u li ọ̀pọlọpọ ati fun awọn enia
pẹlu rẹ, o si rọ̀ ọ lati ba a gòke lọ si
.oti-Gileadi.
Ahabu ọba Israeli si wi fun Jehoṣafati
Juda pe, Iwọ o ha ba mi lọ si Ramoti-
adi bi? On si da a li ohùn wipe, Emi
vọ, ati enia mi bi enia rẹ; awa o pẹlu
ogun na.
Jehoṣafati si wi fun ọba Israeli pe,
bẹ̀ ọ, bère ọ̀rọ Oluwa loni.
Nitorina ọba Israeli kó awọn woli jọ,
wo ọkọnrin, o si wi fun wọn pe, Ki
ki o ha lọ si Ramoti-Gileadi lọ ijagun,
ki emi ki o jọwọ rẹ̀? Nwọn si wipe,
e lọ; Ọlọrun yio si fi i le ọba lọwọ.
Ṣugbọn Jehoṣafati wipe, Kò si woli
wa nihin pẹlu, ti awa iba bère lọwọ rẹ̀?
Ọba Israeli si wi fun Jehoṣafati pe,
nrin kan mbẹ sibẹ lọdọ ẹniti awa iba
ɔ lọwọ Oluwa: ṣugbọn emi korira rẹ̀:
ɔriti kò jẹ sọ asọtẹlẹ rere si mi lai, bi-
e ibi nigbagbogbo: eyini ni Mikaiah,
ɔ Imla. Jehoṣafati si wipe, Ki ọba ki
ıá sọ bẹ̃.
Ọba Israeli si pè ìwẹfa kan, o si wipe,
ki Mikaiah ọmọ Imla, ki o yara wá.
Ati ọba Israeli, ati Jehoṣafati, ọba
la joko, olukuluku lori itẹ rẹ̀, nwọn si
aṣọ igunwa wọn, nwọn si joko ni ita

ẹnu-bọde Samaria; gbogbo awọn woli si
nsọ asọtẹlẹ niwaju wọn.
10 Sedekiah ọmọ Kenaana si ṣe iwo irin
o si wipe, Bayi li Oluwa wi, Wọnyi ni iwọ
o fi kàn awọn ara Siria titi iwọ o fi run
wọn.
11 Gbogbo awọn woli si nsọtẹlẹ bẹ̃ wipe,
Gòke lọ si Ramoti-Gileadi, iwọ o ṣe rere;
Oluwa yio si fi i le ọba lọwọ.
12 Onṣẹ ti o lọ ipè Mikaiah si wi fun u
pe, Kiye si i, awọn woli fi ẹnu kan sọ rere
fun ọba: Njẹ emi bẹ̀ ọ, jẹ ki ọ̀rọ rẹ ki o
dabi ọkan ninu ti wọn, ki o si sọ rere.
13 Mikaiah si wipe, Bi Oluwa ti mbẹ,
ani, eyiti Ọlọrun mi ba wi li emi o sọ.
14 Nigbati o si tọ̀ ọba wá, ọba sọ fun u
pe, Mikaiah, ki awa ki o lọ si Ramoti-
Gileadi lọ ijagun, tabi ki emi ki o jọwọ
rẹ̀? O si wipe, Ẹ lọ, ẹnyin o si ṣe rere, a
o si fi wọn le nyin lọwọ.
15 Ọba si wi fun u pe, Igba melo li emi
o fi ọ bú ki iwọ ki o máṣe sọ ohun kan fun
mi bikòṣe ọ̀rọ otitọ li orukọ Oluwa?
16 On si wipe, Emi ri gbogbo Israeli
fọnka kiri lori awọn òke, bi agutan ti kò
ni oluṣọ: Oluwa si wipe, Awọn wọnyi kò
ni oluwa: jẹ ki nwọn ki o pada, olukuluku
si ile rẹ̀ li alafia.
17 Ọba Israeli si wi fun Jehoṣafati pe,
Emi kò ti wi fun ọ pe: on kì isọtẹlẹ rere
si mi, bikòṣe ibi?
18 On si wipe, Nitorina, gbọ́ ọ̀rọ Oluwa:
mo ri Oluwa joko lori itẹ́ rẹ̀, ati gbogbo
ogun ọrun duro lapa ọtún ati lapa òsi rẹ̀.
19 Oluwa si wipe, Tani yio tàn Ahabu,
ọba Israeli, ki o le gòke lọ ki o si le ṣubu
ni Ramoti-Gileadi? Ekini si ṣo bayi, ekeji
si sọ miran.
20 Nigbana ni ẹmi na jade wá, o si duro
niwaju Oluwa, o si wipe, Emi o tàn a.
Oluwa si wi fun u pe, Bawo?
21 On si wipe, Emi o jade lọ, emi o si
di ẹmi eke li ẹnu gbogbo awọn woli rẹ̀.
Oluwa si wipe, Iwọ o tàn a, iwọ o si bori
pẹlu: jade lọ, ki o si ṣe bẹ̃ na.
22 Njẹ nisisiyi, kiyesi i, Oluwa ti fi ẹmi
eke si ẹnu gbogbo awọn wọli rẹ wọnyi,
Oluwa si ti sọ ibi si ọ.
23 Nigbana ni Sedekiah, ọmọ Kenaana,
sunmọ ọ, o si lù Mikaiah li ẹrẹkẹ, o si
wipe, Ọna wo li ẹmi Oluwa gbà kọja lọ
kuro lọdọ mi lati ba ọ sọrọ.
24 Mikaiah si wipe, Kiyesi i, iwọ o ri i
li ọjọ na, nigbati iwọ o wọ inu iyẹwu de
inu iyẹwu lọ ifi ara rẹ pamọ́,
25 Nigbana ni ọba Israeli wipe, Ẹ mu

Digitized by Google

Mikaiah, ki ẹ si mu u pada sọdọ Amoni,
olori ilu, ati sọdọ Joaṣi, ọmọ ọba.
26 Ki ẹ si wipe, Bayi li ọba wi, ẹ fi
eleyi sinu tubu, ki ẹ si fi ọnjẹ ipọnju ati
omi ipọnju bọ́ ọ, titi emi o fi pada bọ̀ li
alafia.
27 Mikaiah si wipe, Ni pipada bi iwọ
ba pada bọ̀ li alafia, njẹ Oluwa kò ti ọdọ
mi sọ̀rọ. O si wipe, Ẹ gbọ́, ẹnyin enia
gbogbo.
28 Bẽli ọba Israeli ati Jehoṣafati, ọba
Juda, si gòke lọ si Ramoti-Gileadi.
29 Ọba Israeli si wi fun Jehoṣafati pe,
emi o pa aṣọ dà, emi o si lọ si oju ìja;
ṣugbọn iwọ gbé aṣọ igunwà rẹ wọ̀. Bẽli
ọba Israeli si pa aṣọ dà; nwọn si lọ si oju
ìja.
30 Ṣugbọn ọba Siria ti paṣẹ fun awọn
olori kẹkẹ́ ti o wà lọdọ rẹ̀, pe, Ẹ máṣe ba
ewe tabi àgba jà, bikòṣe ọba Israeli nikan.
31 O si ṣe, nigbati awọn olori kẹkẹ́ ri
Jehoṣafati, ni nwọn wipe eyi li ọba Israeli,
nitorina nwọn yi i ka lati ba a jà: ṣugbọn
Jehoṣafati kigbe, Oluwa si ràn a lọwọ:
Ọlọrun si yi wọn pada kuro lọdọ rẹ̀.
32 O si ṣe, bi awọn olori kẹkẹ́ ti woye
pe kì iṣe ọba Israeli, nwọn yipada kuro
lẹhin rẹ̀.
33 Ọkọnrin kan si fa ọrun rẹ̀ laipete, o
si ta ọba Israeli lãrin ipade ẹwu-irin, o si
wi fun olutọju kẹkẹ́ rẹ̀ pe, Yi ọwọ rẹ pada,
ki o mu mi jade kuro loju ìja; nitoriti mo
gbọgbẹ.
34 Ija na si pọ̀ li ọjọ na: pẹlupẹlu ọba
Israeli duro ninu kẹkẹ́ rẹ̀ kọju si awọn ara
Siria titi di aṣãlẹ: o si kú li akokò ìwọ
õrun.

## ORI 19.

JEHOṢAFATI, ọba Juda, si pada lọ si ile
rẹ̀ ni Jerusalemu li alafia.
2 Jehu, ọmọ Hanani, ariran, si jade lọ
ipade rẹ̀, o si wi fun Jehoṣafati pe, iwọ o
ha ma ràn enia buburu lọwọ, iwọ o si fẹran
awọn ti o korira Oluwa? njẹ nitori eyi ni
ibinu ṣe de si ọ lati ọdọ Oluwa.
3 Ṣugbọn a ri ohun rere ninu rẹ, pe,
nitori ti iwọ ti mu awọn ere-oriṣa kuro
ni ilẹ na, ti o si mura ọkàn rẹ lati wá
Ọlọrun.
4 Jehoṣafati si ngbe Jerusalemu: o nlọ,
o mbọ̀ lãrin awọn enia lati Beerṣeba de òke
Efraimu, o si mu wọn pada sọdọ Oluwa,
Ọlọrun awọn baba wọn.
5 O si fi awọn onidajọ si ilẹ na, ninu
gbogbo ilu olodi Juda, lati ilu de ilu,
6 O si wi fun awọn onidajọ pe, Ẹ kiyesi
ohun ti ẹnyin nṣe! nitori ti ẹnyin kò dajọ
fun enia bikòṣe fun Oluwa, ti o wà pẹlu
nyin ninu ọ̀ran idajọ.
7 Njẹ nisisiyi, jẹ ki ẹ̀ru Oluwa ki o wà
lara nyin, ẹ ma ṣọra, ki ẹ si ṣe e; nitoriti
kò si aiṣedede kan lọdọ Oluwa Ọlọrun wa,
tabi ojusaju enia, tabi gbigba abẹtẹlẹ.
8 Pẹlupẹlu ni Jerusalemu, Jehoṣafati yàn
ninu awọn ọmọ Lefi, ati ninu awọn alufa,
ati ninu awọn olori awọn baba Israeli, fun
idajọ Oluwa, ati fun ẹjọ; nwọn si ngbe
Jerusalemu.
9 O si kilọ fun wọn, wipe, Bayi ni ki
ẹnyin ki o mã ṣe, ni ibẹ̀ru Oluwa, li otitọ,
ati pẹlu ọkàn pipé.
10 Ẹjọ ki ẹjọ ti o ba si de ọdọ nyin lati
ọdọ awọn arakọnrin nyin ti ngbe ilu wọn,
lãrin ẹ̀jẹ on ẹ̀jẹ, lãrin ofin pẹlu aṣẹ, ìlana
ati ẹtọ́, ki ẹnyin ki o kilọ fun wọn, ki nwọn
ki o máṣe dẹṣẹ si Oluwa, ibinu a si wá sori
nyin, ati sori awọn arakọnrin nyin: ẹ ṣe
bẹ̃ gẹgẹ, ẹnyin kì yio si jẹbi.
11 Si wõ, Amariah, alufa ni olori lori
nyin ni gbogbo ọ̀ran Oluwa; ati Sebadiah,
ọmọ Iṣmaeli, alakoso ile Juda, fun ọ̀ran
ọba; pẹlupẹlu ẹnyin ni olutọju awọn ọmọ
Lefi pẹlu nyin. Ẹ mu ara le, ki ẹ si ṣe,
Oluwa yio pẹlu ẹni-rere.

## ORI 20.

O SI ṣe, lẹhin eyi li awọn ọmọ Moabu,
ati awọn ọmọ Ammoni, ati ninu awọn
ọmọ Edomu pẹlu wọn, gbé ogun tọ Jeho-
ṣafati wá.
2 Nigbana li awọn kan wá, nwọn si wi
fun Jehoṣafati pe, Ọpọlọpọ enia mbọ wá
ba ọ lati apakeji okun lati Siria, si ki-
yesi i, nwọn wà ni Hasason-Tamari ti iṣe
Engedi.
3 Jehoṣafati si bẹ̀ru, o si fi ara rẹ̀ si
ati wá Oluwa, o si kede àwẹ ja gbogbo
Juda.
4 Juda si kó ara wọn jọ, lati wá iranlọwọ
lọwọ Oluwa: pẹlupẹlu nwọn wá lati inu
gbogbo ilu Juda lati wá Oluwa,
5 Jehoṣafati si duro ninu apejọ enia Juda
ati Jerusalemu, ni ile Oluwa, niwaju àgba-
la titun.
6 O si wipe, Oluwa, Ọlọrun awọn baba
wa, iwọ kọ́ ha ṣe Ọlọrun li ọrun? Iwọ kọ́
ha nṣakoso lori gbogbo ijọba awọn orilẹ-
ède? lọwọ rẹ ki agbara ati ipá ha wà, ti
ẹnikan kò si, ti o le kò ọ loju?
7 Iwọ ha kọ́ Ọlọrun wa, ti o ti le awọn

Digitized by Google

yi jade niwaju Israeli enia rẹ, ti o si
.ru-ọmọ Abrahamu, ọrẹ rẹ lailai?
wọn si ngbe inu rẹ̀, nwọn si kọ́ ibi-
fun ọ ninu rẹ̀ fun orukọ rẹ, pe,
i ibi ba de si wa, bi idà, ijiya tabi
ẹ-àrun, tabi ìyan, bi awa ba duro
ı ile yi, ati niwaju rẹ, (nitori orukọ
ni ile yi): bi a ba ke pè ọ ninu wà-
'a, nigbana ni iwọ o gbọ́, iwọ o si ṣe
ʋọ.
Njẹ nisisiyi, kiyesi i, awọn ọmọ Am-
ati Moabu, ati awọn ara òke Seiri, ti
) jẹ ki Israeli gbogun si nigbati nwọn
i ilẹ Egipti wá, ṣugbọn nwọn yipada
.ọdọ wọn, nwọn kò si run wọn;
Si kiyesi i, bi nwọn ti san a pada fun
ati wá le wa jade kuro ninu ini rẹ, ti
fi fun wa lati ni.
Ọlọrun wa! Iwọ kì o ha da wọn
nitori awa kò li agbara niwaju ọ̀pọ-
ıla yi; ti mbọ̀ wá ba wa; awa kò si
yi ti awa o ṣe: ṣugbọn oju wa mbẹ
ẹ.
Gbogbo Juda si duro niwaju Oluwa,
awọn ọmọ wẹrẹ wọn, obirin wọn, ati
wọn.
Ṣugbọn lori Jahasieli, ọmọ Sekariah,
Benaiah, ọmọ Jeieli, ọmọ Mattaniah,
Lefi kan ninu awọn ọmọ Asafu, ni ẹmi
'a wá li ãrin apejọ enia na.
O si wipe, Ẹ tẹti silẹ, gbogbo Juda,
nyin olugbe Jerusalemu, ati iwọ Jeho-
i ọba; Bayi li Oluwa wi fun nyin, Ẹ
: bẹ̀ru, bẹ̃ni ki ẹ má si ṣe fòya nitori
ọpọ enia yi; nitori ogun na kì iṣe ti
bikòṣe ti Ọlọrun.
Lọla sọ̀kalẹ tọ̀ wọn: kiyesi i, nwọn o
ibi igòke Sisi wá; ẹnyin o si ri wọn ni
un odò na, niwaju aginju Jerueli.
Ẹnyin kò ni ijà li ọ̀ràn yi; ẹ tẹgun, ẹ
jẹ, ki ẹ si ri igbala Oluwa lọdọ nyin,
Juda ati Jerusalemu: ẹ máṣe bẹ̀ru,
ki ẹ má si ṣe fòya: lọla, ẹ jade tọ̀
: Oluwa yio si pẹlu nyin.
3 Jehoṣafati tẹ ori rẹ̀ ba silẹ: ati gbo-
Juda, ati awọn olugbe Jerusalemu wolẹ
aju Oluwa lati sìn Oluwa.
9 Awọn ọmọ Lefi, ninu awọn ọmọ Ko-
. ati ninu awọn ọmọ Kori si dide duro,
fi ohùn rara kọrin iyìn soke si Oluwa
run Israeli.
0 Nwọn si dide ni kutukutu owurọ,
ın si jade lọ si aginju Tekoa: bi nwọn
i jade lọ, Jehoṣafati duro, o si wipe, Ẹ
temi, ẹnyin ará Juda, ati ẹnyin olugbe
usalemu. Ẹ gbà Oluwa Ọlọrun nyin
gbọ́, bẹ̃li a o fi ẹsẹ nyin mulẹ; ẹ gbà awọn
woli rẹ̀ gbọ́, bẹ̃li ẹnyin o ṣe rere.
21 O si ba awọn enia na gbero, o yàn
awọn akọrin si Oluwa, ti yio ma yìn ẹwa
ìwa-mimọ́ bi nwọn ti njade lọ niwaju ogun
na, ati lati ma wipe, Ẹ yìn Oluwa: nito-
riti ãnu rẹ̀ duro lailai.
22 Nigbati nwọn bẹ̀rẹ si ikọrin ati si
iyìn, Oluwa yàn ogun-ẹhin si awọn ọmọ
Ammoni, Moabu ati awọn ara òke Seiri, ti
o wá si Juda, a si kọlù wọn.
23 Awọn ọmọ Ammoni ati Moabu si
dide si awọn ti ngbe òke Seiri, lati pa, ati
lati run wọn tũtu: nigbati nwọn si pa
awọn ti ngbe òke Seiri run tan, ẹnikini nṣe
iranlọwọ lati run ẹnikeji.
24 Nigbati Juda si de iha ile-iṣọ li agin-
ju, nwọn wò awọn ọ̀pọlọpọ enia, si kiyesi i,
okú ti o ṣubu lulẹ ni nwọn, ẹnikan kò sá
asalà.
25 Nigbati Jehoṣafati ati awọn enia rẹ̀
de lati kó ikogun wọn, nwọn ri lara wọn
ọ̀pọlọpọ ọrọ̀, ati okú, ati ohun-elo iyebiye,
nwọn si kójọ fun ara wọn, jù eyiti nwọn le
kó lọ: nwọn si kó ikogun wọn jọ ni ijọ
mẹta, nitoriti o sa papọ̀ju.
26 Ati li ọjọ kẹrin nwọn kó ara wọn jọ
li afonifoji Ibukún, nitori nibẹ ni nwọn fi
ibukún fun Oluwa, nitorina ni a ṣe npe
orukọ ibẹ na ni, Afonifoji Ibukún, titi di
oni.
27 Nigbana ni nwọn yipada, gbogbo
awọn ọkọnrin Juda ati Jerusalemu, ati
Jehoṣafati niwaju wọn lati pada lọ si Jeru-
salemu pẹlu ayọ̀; nitori ti Oluwa ti mu
wọn yọ̀ lori awọn ọta wọn.
28 Nwọn si wá si Jerusalemu pẹlu ohun-
elo orin, ati duru ati ipè si ile Oluwa.
29 Ibẹ̀ru Ọlọrun si wà lara gbogbo ijọba
ilẹ wọnni, nigbati nwọn gbọ́ pe Oluwa ti ba
awọn ọta Israeli jà.
30 Bẹ̃ni ijọba Jehoṣafati wà li alafia:
nitoriti Ọlọrun rẹ̀ fun u ni isimi yika-
kiri.
31 Jehoṣafati si jọba lori Juda: o si wà
li ẹni ọdun marundilogoji, nigbati o bẹ̀rẹ
si ijọba, o si jọba ọdun mẹdọgbọn ni Jeru-
salemu. Orukọ iya rẹ̀ si ni Asuba, ọmọbi-
rin Ṣilhi.
32 O si rìn li ọ̀na Asa, baba rẹ̀, kò si
yà kuro ninu rẹ̀, o nṣe eyi ti o tọ́ li oju
Oluwa.
33 Sibẹ kò mu ibi giga wọnni kuro:
pẹlupẹlu awọn enia na kò si fi ọkàn wọn
fun Ọlọrun awọn baba wọn rara.
34 Ati iyokù iṣe Jehoṣafati, ti iṣaju ati

Digitized by Google

ti ikẹhin, kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe Jehu,
ọmọ Hanani, a si ti fi i sinu iwe awọn ọba
Israeli.
35 Ati lẹhin eyi ni Jehoṣafati, ọba Juda,
dà ara rẹ̀ pọ̀ mọ Ahasiah, ọba Israeli, ẹniti
o ṣe buburu gidigidi :
36 O si dà ara rẹ̀ pọ̀ mọ ọ lati kan ọkọ̀
lati lọ si Tarṣiṣi : nwọn si kàn ọkọ̀ ni Esion-
Geberi.
37 Nigbana ni Elieseri ọmọ Dodafah ti
Mareṣa sọtẹlẹ si Jehoṣafati wipe, Nitori ti
iwọ ti dá ara rẹ pọ̀ mọ Ahasiah, Oluwa ti
ba iṣẹ rẹ jẹ. Awọn' ọkọ̀ na si fọ́, nwọn kò
si le lọ si Tarṣiṣi.

## ORI 21.

JEHOṢAFATI si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀,
a si sin i pẹlu awọn baba rẹ̀ ni ilu
Dafidi : Jehoramu ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò
rẹ̀.
2 O si ni awọn arakọnrin, awọn ọmọ
Jehoṣafati, Asariah, ati Jehieli, ati Seka-
riah, ati Asariah ati Mikaeli, ati Ṣefatiah :
gbogbo awọn wọnyi li awọn ọmọ Jehoṣafati,
ọba Juda.
3 Baba wọn si bun wọn li ẹ̀bun pupọ, ni
fadakà ati ni wura, ati ohun iyebiye, pẹlu
ilu olodi ni Juda, ṣugbọn o fi ijọba fun Je-
horamu : nitori on li akọbi.
4 Nigbati Jehoramu si dide si ijọba baba
rẹ̀, o mu ara rẹ̀ le, o si fi idà pa gbogbo
awọn arakọnrin rẹ̀, ati ninu awọn ijoye
Israeli.
5 Jehoramu jẹ ẹni ọdun mejilelọgbọ̀n
nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba li ọdun
mẹjọ ni Jerusalemu.
6 O si rìn li ọ̀na awọn ọba Israeli, gẹgẹ
bi ile Ahabu ti ṣe : nitoriti o ni ọmọbirin
Ahabu li aya : o si ṣe eyiti o buru li oju
Oluwa.
7 Ṣugbọn Oluwa kò fẹ ipa ile Dafidi run,
nitori majẹmu ti o ti ba Dafidi da, ati bi o
ti ṣe ileri lati fun u ni imọlẹ kan ati fun
awọn ọmọ rẹ̀ lailai.
8 Li ọjọ rẹ̀ li awọn ara Edomu ṣọ̀tẹ kuro
labẹ ọwọ Juda, nwọn si jẹ ọba fun ara wọn.
9 Nigbana ni Jehoramu rekọja lọ pẹlu
awọn ijoye rẹ̀, ati gbogbo kẹkẹ́ rẹ̀ pẹlu rẹ̀ :
o si dide li oru, o si kọlù awọn ara Edomu
ti o ká a mọ, ati awọn olori kẹkẹ́.
10 Sibẹ awọn ara Edomu ṣọ̀tẹ kuro labẹ
ọwọ Juda, titi di oni yi. Akokò na pẹlu
ni Libna ṣọ̀tẹ kuro labẹ ọwọ rẹ̀ ; nitoriti o
ti kọ̀ Oluwa, Ọlọrun awọn baba rẹ̀ silẹ.
11 Pẹlupẹlu o ṣe ibi giga wọnni lori òke
Juda, o si mu ki awọn olugbe Jerusalemu
ki o ṣe àgbere, o si mu Juda ṣẹ̀.
12 Iwe kan si ti ọdọ Elijah, woli, wá si
ọdọ rẹ̀ wipe : Bayi li Oluwa, Ọlọrun Dafidi
baba rẹ wi, nitoriti iwọ kò rìn li ọ̀na Jeho-
ṣafati, baba rẹ, tabi li ọ̀na Asa, ọba Juda ;
13 Ṣugbọn ti iwọ rìn li ọ̀na awọn ọba
Israeli, iwọ si ti mu Juda ati awọn olugbe
Jerusalemu tọ ọ̀na panṣaga, gẹgẹ bi panṣa-
ga ile Ahabu, ati ti iwọ si pa awọn arakọn-
rin ile baba rẹ ti o jẹ ẹni-rere jù iwọ lọ :
14 Kiyesi i, Oluwa yio fi àjakalẹ-arun
nla kọlù awọn enia rẹ, ati awọn ọmọ rẹ, ati
awọn obirin rẹ, ati gbogbo ọrọ̀ rẹ :
15 Iwọ o ṣe aisan pupọ, àrun nla ninu
ifun rẹ, titi ifun rẹ yio fi tu jade nitori
àrun ọjọ pupọ.
16 Pẹlupẹlu, Oluwa ru ẹmi awọn ara
Filistia, ati ti awọn ara Arabia, ti o sunmọ
awọn ara Etiopia, soke si Jehoramu.
17 Nwọn si gòke wá si Juda, nwọn si
ya wọle, nwọn si kó gbogbo ọrọ̀ ti a ri ni
ile ọba ati awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu, ati awọn
obirin rẹ̀, ni igbekun lọ ; tobẹ̃ ti a kò kù
ọkọnrin kan silẹ fun u, bikòṣe Jehoahasi,
abikẹhin ninu awọn ọmọ rẹ̀.
18 Lẹhin gbogbo eyi Oluwa fi àrun, ti a
kò le wòsan, kọlù u ni ifun.
19 O si ṣe bẹ̃ bi akokò ti nlọ ati lẹhin
ọdun meji, ni ifun rẹ̀ tu jade nitori aisan
rẹ̀, o si kú ninu irora buburu na : awọn
enia rẹ̀ kò si ṣe ijona fun u gẹgẹ bi ijona ti
awọn baba rẹ̀.
20 Ẹni ọdun mejilelọgbọn ni nigbati o
bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun mẹjọ ni Jeru-
salemu, o si fi ilẹ silẹ laiwu ni : nwọn si
sin i ni ilu Dafidi ; ṣugbọn ki iṣe ninu
iboji awọn ọba.

## ORI 22.

AWỌN olugbe Jerusalemu, si fi Ahasiah,
ọmọ rẹ̀ abikẹhin, jọba ni ipò rẹ̀ : ni-
tori awọn ẹgbẹ́ ogun, ti o ba awọn ara
Arabia wá ibudo, ti pa gbogbo awọn ẹgbọn.
Bẹ̃ni Ahasiah, ọmọ Jehoramu, ọba Juda,
jọba.
2 Ẹni ọdun mejilelogun ni Ahasiah,
nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun kan
ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ si ni Ataliah,
ọmọbirin Omri.
3 On pẹlu rìn li ọ̀na Ahabu : nitori iya
rẹ̀ ni igbimọ̀ rẹ̀ lati ṣe buburu.
4 O si ṣe buburu loju Oluwa bi ile
Ahabu : nitori awọn wọnyi li o nṣe igbimọ̀
rẹ̀ lẹhin ikú baba rẹ̀ si iparun rẹ̀.
5 O tẹle imọ̀ran wọn pẹlu ; o si ba Je-

Digitized by Google

ıu, ọmọ Ahabu, ọba Israeli, lọ iba
ıli, ọba Siria jagun, ni Ramoti-Gi-
: awọn ara Siria si ṣá Jehoramu li

) si pada lọ iwora ni Jesreeli, nitori
ti a ṣá a ni Rama, nigbati o fi ba
ıli, ọba Siria jà. Ahasiah, ọmọ Jeho-
, ọba Juda, si sọ̀kalẹ lọ iwò Jehoramu,
Ahabu, ni Jesreeli, nitoriti o ṣaisan.
.parun Ahasiah lati ọwọ Ọlọrun wá
ipa wiwá sọdọ Jehoramu: nigbati o si
si ba Jehoramu jade tọ̀ Jehu, ọmọ
ıi, ẹniti Oluwa fi ororo yàn lati kè ile
u kuro.
) si ṣe nigbati Jehu nmu idajọ ṣẹ sori
ıabu, o si ri awọn ijoye Juda, ati awọn
awọn arakọnrin Ahasiah, ti nṣe iranṣẹ
hasiah, o si pa wọn.
) si wá Ahasiah: nwọn si mu u, (on
fi ara pamọ́ ni Samaria,) nwọn si mu
Jehu wá: nigbati nwọn si pa a tan,
ı sìn i: nitori ti nwọn wipe, ọmọ
ṣafati ni, ẹniti o wá Oluwa tọkàntọkan
Bẹ̃ni kò si ẹnikan ni ile Ahasiah ti o
n ijọba.
Ṣugbọn nigbati Ataliah, iya Ahasiah,
ọmọ on kú, o dide o si run gbogbo iru
ijọba ile Juda.
Ṣugbọn Jehoṣabeati, ọmọbirin ọba,
Joaṣi, ọmọ Ahasiah, ji i kuro ninu
ı ọmọ ọba ti a pa, o fi on ati olutọ rẹ̀
yẹwu Ibusùn. Bẹ̃ni Jehoṣabeati,
ɔirin Jehoramu ọba, aya Jehoiada,
ı, (nitori arabirin Ahasiah li on) o pa
kuro lọdọ Ataliah ki o má ba pa a.
O si wà pẹlu wọn ni pipamọ́ ninu ile
un li ọdun mẹfa: Ataliah si jọba lori
a.

## ORI 23.

I li ọdun keje, Jehoiada mu ọkàn le, o
si ba awọn olori ọrọrun dá majẹmu
, ani Asariah, ọmọ Jerohamu ati Iṣma-
ọmọ Jehohanani, ati Asariah ọmọ
li, ati Maaseiah, ọmọ Adaiah, ati
ıfati ọmọ Sikri.
Nwọn si lọ kakiri ni Juda, nwọn si kó
ı ọmọ Lefi jọ lati inu gbogbo ilu Juda,
lori awọn baba ni Israeli, nwọn si wá
rusalemu.
Gbogbo ijọ enia si ba ọba dá majẹmu
e Ọlọrun. O si wi fun wọn pe, Kiyesi
nọ ọba ni yio jọba, gẹgẹ bi Oluwa ti wi
awọn ọmọ Dafidi.
Eyi li ohun ti ẹnyin o ṣe; Idamẹta
nyin yio wọle li ọjọ isimi, ninu awọn alufa
ati ninu awọn ọmọ Lefi, ti yio ṣe adena
iloro:
5 Idamẹta yio wà ni ile ọba: idamẹta
yio si wà li ẹnu-ọ̀na ti a npè ni ile Ipilẹ:
ati gbogbo enia yio wà li àgbala ile Oluwa.
6 Ṣugbọn ẹ máṣe jẹ ki ẹnikan ki o wọ̀
ile Oluwa wá, bikoṣe awọn alufa, ati awọn
ti nṣe iranṣẹ fun awọn ọmọ Lefi: nwọn o
wọle, nitori mimọ́ ni nwọn: gbogbo awọn
enia yio si ṣọ́ ẹṣọ́ Oluwa.
7 Awọn ọmọ Lefi yio yi ọba ka kakiri,
olukuluku pẹlu ohun ijà rẹ̀ li ọwọ rẹ̀: ẹni-
kẹni ti o ba wá si iha ile na, a o si pa a:
ṣugbọn ki ẹnyin ki o wà pẹlu ọba, nigbati
o ba nwọ̀ ile, ati nigbati o ba njade.
8 Bẹ̃li awọn ọmọ Lefi ati gbogbo Juda
ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti Jehoiada, alufa ti
pa li aṣẹ, olukuluku si mu awọn enia rẹ̀ ti
o nwọle li ọjọ isimi, pẹlu awọn ti o njade li
ọjọ isimi nitori Jehoiada alufa, kò jọwọ
awọn ẹgbẹ meji alufa lọwọ lọ.
9 Jehoiada alufa, si fi ọ̀kọ ati asà, ati
apata wọnni ti iti ṣe ti Dafidi ọba, ti o
ti wà ni ile Ọlọrun, fun awọn balogun
ọrọrun.
10 O si tò gbogbo awọn enia ti ọba ka-
kiri olukuluku pẹlu ohun ijà rẹ̀ li ọwọ rẹ̀,
lati apa ọtún ile na titi de apa òsi ile na,
lẹba pẹpẹ ati lẹba ile na.
11 Nigbana ni nwọn mu ọmọ ọba jade
wá, nwọn si fi ade fun u ati iwe ẹri na,
nwọn si fi i jọba: Jehoiada ati awọn ọmọ
rẹ̀ si fi ororo yàn a, nwọn si wipe, Ki ọba
ki o pẹ.
12 Nigbati Ataliah gbọ́ ariwo awọn enia,
ti nwọn nsare lọ sibẹ, ti nwọn si nyìn ọba,
o si tọ̀ awọn enia na wá sinu ile Oluwa:
13 O si wò, si kiyesi i, ọba duro ni ibu-
duro rẹ̀ li ẹba ẹnu-ọ̀na, ati awọn balogun
ati awọn afunpè lọdọ ọba: ati gbogbo
awọn enia ilẹ na si yọ̀, nwọn si fun ipè, ati
awọn akọrin pẹlu ohun-elo orin, ati awọn
ti nkede lati kọ orin iyin. Nigbana ni
Ataliah fa aṣọ rẹ̀ ya, o si wipe: Ọtẹ!
Ọtẹ!
14 Nigbana ni Jehoiada alufa mu awọn
olori ọrọrun ani awọn olori ogun na jade,
o si wi fun wọn pe, Ẹ mu u jade kuro ninu
ile sẹhin àgbala: ẹnikẹni ti o ba si tọ̀ ọ
lẹhin, ni ki a fi idà pa. Nitori alufa wipe,
Ẹ máṣe pa a ninu ile Oluwa.
15 Nwọn si fi àye fun u; nigbati o si
de atiwọ̀ ẹnu-ọ̀na Ẹṣin ile ọba, nwọn si pa
a nibẹ.
16 Jehoiada dá majẹmu lãrin on ati

Digitized by Google

lãrin awọn enia, ati lãrin ọba pe, enia Olu-
wa li awọn o ma ṣe.
17 Gbogbo awọn enia na si lọ si ile
Baali, nwọn si wó o lulẹ, nwọn si fọ pẹpẹ
ati awọn ere rẹ̀ tũtu, nwọn si pa Mattani
alufa Baali, niwaju pẹpẹ.
18 Jehoiada si fi iṣẹ itọju ile Oluwa le
ọwọ awọn alufa, awọn ọmọ Lefi, ti Dafidi
ti pin lori ile Oluwa, lati ma ru ẹbọ ọrẹ
sisun Oluwa, bi a ti kọ ọ ninu ofin Mose,
pẹlu ayọ̀ ati pẹlu orin lati ọwọ Dafidi.
19 O si fi awọn adena si ẹnu-ọ̀na ile
Oluwa, ki ẹni alaimọ́ ninu ohunkohun ki
o má ba wọ̀ ọ.
20 O si mu awọn olori-ọrọrun, ati awọn
ọlọla, ati awọn bãlẹ ninu awọn enia ati
gbogbo enia ilẹ na, nwọn si mu ọba sọ̀kalẹ
lati ile Oluwa wá: nwọn si gbà ẹnu-ọ̀na
giga wá sinu ile ọba, nwọn si gbé ọba ka
ori itẹ ijọba na.
21 Gbogbo awọn enia ilẹ na si yọ̀: ilu
na si tòro lẹhin ti a fi idà pa Ataliah.

ORI 24.

ENI ọdun meje ni Joaṣi nigbati o bẹ̀rẹ si
ijọba, o si jọba ogoji ọdun ni Jerusale-
mu. Orukọ iya rẹ̀ si ni Sibia ti Beer-ṣeba.
2 Joaṣi si ṣe eyiti o tọ li oju Oluwa ni
gbogbo ọjọ Jehoiada, alufa.
3 Jehoiada si fẹ obirin meji fun u, o si
bi ọmọkọnrin ati ọmọbirin.
4 O si ṣe lẹhin eyi, o wà li ọkàn Joaṣi
lati tun ile Oluwa ṣe.
5 O si kó awọn alufa ati awọn ọmọ Lefi
jọ, o si wi fun wọn pe, Ẹ jade lọ si ilu
Juda wọnni, ki ẹ́ si gbà owo jọ lati ọwọ
gbogbo Israeli, lati tun ile Ọlọrun nyin ṣe
li ọdọdun, ki ẹ si mu ọ̀ran na yá kankan.
Ṣugbọn awọn ọmọ Lefi kò mu ọ̀ran na yá
kánkan.
6 Ọba si pè Jehoiada, olori, o si wi fun
u pe, Ẽṣe ti iwọ kò bère li ọwọ awọn ọmọ
Lefi, ki nwọn ki o mu owo ofin Mose,
iranṣẹ Oluwa, lati Juda ati lati Jerusalemu
wá, ati ti ijọ enia Israeli fun agọ ẹri?
7 Nitori Ataliah, obirin buburu nì ati
awọn ọmọ rẹ ti fọ ile Ọlọrun; ati pẹlu
gbogbo ohun mimọ́ ile Oluwa ni nwọn fi ṣe
isin fun Baalimu.
8 Ọba si paṣẹ, nwọn si kàn apoti kan,
nwọn si fi si ita li ẹnu-ọ̀na ile Oluwa.
9 Nwọn si kede ni Juda ati Jerusalemu,
lati mu owo ofin fun Oluwa wá, ti Mose
iranṣẹ Ọlọrun, fi le Israeli lori li aginju,
10 Gbogbo awọn ijoye ati gbogbo awọn
enia si yọ̀, nwọn si mu wá, nwọn fi sinu
apoti na, titi o fi kún.
11 O si ṣe, nigbati akokò de lati mu
apoti na wá sọdọ olutọju iṣẹ ọba nipa ọwọ
awọn ọmọ Lefi, nigbati nwọn si ri pe, owo
pọ̀, akọwe ọba ati olori ninu awọn alufa a
wá, nwọn a si dà apoti na, nwọn a mu u,
nwọn a si tun mu u pada lọ si ipò rẹ̀.
Bayi ni nwọn nṣe li ojojumọ, nwọn si kó
owo jọ li ọ̀pọlọpọ.
12 Ati ọba ati Jehoiada fi i fun iru awọn
ti nṣiṣẹ ile Oluwa, nwọn si fi gbà àgbaṣe
awọn onisọnà okuta, ati awọn gbẹnàgbena,
lati tun ile Oluwa ṣe, ati pẹlu awọn ala-
gbẹdẹ irin, ati idẹ, lati tun ile Oluwa ṣe.
13 Bẹ̃li awọn ti o nṣiṣẹ ṣiṣẹ na, iṣẹ na si
lọ siwaju ati siwaju li ọwọ wọn, nwọn si
tun mu ile Ọlọrun duro si ipò rẹ, nwọn si
mu u le.
14 Nigbati nwọn si pari rẹ̀ tan, nwọn
mu owo iyokù wá si iwaju ọba ati Jehoiada,
a si fi i ṣe ohun-elo fun ile Oluwa, ani
ohun-elo fun ìsin ati fun ẹbọ, pẹlu ọpọ́n,
ani ohun-elo wura ati fadakà. Nwọn si ru
ẹbọ sisun ni ile Oluwa nigbagbogbo ni
gbogbo ọjọ Jehoiada.
15 Ṣugbọn Jehoiada di arugbo, o si kún
fun ọjọ, o si kú, ẹni ãdoje ọdun ni nigbati
o kú.
16 Nwọn si sìn i ni ilu Dafidi pẹlu awọn
ọba, nitoriti o ṣe rere ni Israeli, ati si
Ọlọrun, ati si ile rẹ̀.
17 Lẹhin ikú Jehoiada awọn ijoye Juda
de, nwọn si tẹriba fun ọbà. Nigbana li
ọba si gbọ́ ti wọn.
18 Nwọn si kọ̀ ile Oluwa, Ọlọrun awọn
baba wọn silẹ, nwọn si nsìn ọ̀riṣa ati ere:
ibinu si wá sori Juda ati Jerusalemu nitori
ẹ̀ṣẹ wọn yi.
19 Sibẹ o rán awọn woli si wọn, lati mu
wọn pada tọ̀ Oluwa wá; nwọn si jẹri gbè
wọn; ṣugbọn nwọn kò fi eti si i.
20 Ẹmi Ọlọrun si bà le Sakariah, ọmọ
Jehoiada alufa, ti o duro ni ibi giga jù
awọn enia lọ, o si wi fun wọn pe, Bayi li
Ọlọrun wi pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi ru ofin
Oluwa, ẹnyin kì yio ri ire? nitoriti ẹnyin
ti kọ̀ Oluwa silẹ, on pẹlu si ti kọ̀ nyin.
21 Nwọn si di rikiṣi si i, nwọn si sọ ọ li
okuta nipa aṣẹ ọba li agbala ile Oluwa.
22 Bẹ̃ni Joaṣi, ọba, kò ranti õre ti Jehoi-
ada, baba rẹ, ti ṣe fun u, o si pa ọmọ rẹ̀.
Nigbati o si nkú lọ, o wipe, Ki Oluwa ki
o wò o, ki o si bère rẹ̀.
23 O si ṣe li opin ọdun ni ogun Siria
gòke tọ̀ ọ wá: nwọn si de Juda ati Jerusa-

Digitized by Google

nwọn si pa gbogbo awọn ijoye enia
uro ninu awọn enia na, nwọn si rán
›o ikógun wọn sọdọ ọba Damasku.
Nitori ogun awọn ara Siria dé pẹlu
diẹ, Oluwa si fi ogun ti o pọ̀ gidigidi
n lọwọ, nitoriti nwọn kọ̀ Oluwa, Ọlọ-
wọn baba wọn silẹ. Bẽni nwọn si ṣe
Joaṣi.
Nigbati nwọn si lọ kuro lọdọ rẹ̀,
n sa ti fi i silẹ ninu àrun nla) awọn
ọ rẹ̀ si di rikiṣi si i, nitori ẹ̀jẹ awọn
Jehoiada alufa, nwọn si pa a lori akete
si kú: nwọn si sin i ni ilu Dafidi,
ọn nwọn kọ̀ sin i ni iboji awọn ọba.
Wọnyi li awọn ti o di rikiṣi si i,
di, ọmọ Ṣimeati, obirin ara Ammoni,
ehosabadi, ọmọ Ṣimriti, obirin ara
ɔu.
Njẹ niti awọn ọmọ rẹ̀, ati titobi owo-
ti a fi le e lori, ati atunṣe ile Ọlọrun,
ıi i, a kọ wọn sinu itan iwe awọn ọba.
siah ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 25.

I ọdun mẹdọgbọn ni Amasiah nigbati
o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba li ọdun mọ-
lilọgbọn ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀
Jehoaddani ti Jerusalemu.
O si ṣe eyi ti o tọ li oju Oluwa, ṣugbọn
e pẹlu ọkàn pipé.
O si ṣe, nigbati a fi idi ijọba na mulẹ
u, o pa awọn iranṣẹ rẹ̀ ti o pa ọba,
ı rẹ̀,
Ṣugbọn kò pa awọn ọmọ wọn, ṣugbọn
gẹgẹ bi a ti kọ ọ ninu ofin ninu iwe
e, ti Oluwa ti paṣẹ wipe, Awọn baba
io kú fun awọn ọmọ, bẹ̃li awọn ọmọ kì
kú fun awọn baba, ṣugbọn ỏlukuluku ni
kú nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
Amasiah si kó Juda jọ, o si tò wọn
ṣẹ gẹgẹ bi ile baba wọn, awọn balogun
ẹgbẹrun ati balogun ọrọrun, ani gbogbo
a ati Benjamini, o si ka iye wọn lati
ogun ọdun ati jù bẹ̀ lọ, o si ri wọn li
mẹdogun enia ti a yàn, ti o le jade lọ
gun, ti o si le lo ọ̀kọ ati asà.
O si bẹ̀ ọkẹ marun ogun alagbara
ni ọkọnrin lati inu Israeli wá fun ọgọ-
talenti fadakà.
Ṣugbọn enia Ọlọrun kan tọ̀ ọ wá,
e, Ọba, máṣe jẹ ki ogun Israeli ki o ba
ọ: nitoriti Oluwa kò wà pẹlu Israeli,
gbogbo awọn ọmọ Efraimu.
Ṣugbọn bi iwọ o ba lọ, ma lọ, mu ara
fun ogun na: Ọlọrun yio bì ọ ṣubu
niwaju ọta: Ọlọrun sa li agbara lati ṣe
iranlọwọ, ati lati bì ni ṣubu.
9 Amasiah si wi fun enia Ọlọrun na pe,
ṣugbọn kili awa o ha ṣe nitori ọgọrun
talenti ti mo ti fi fun ẹgbẹ-ogun Israeli?
Enia Ọlọrun na si dahùn pe, o wà li ọwọ
Oluwa lati fun ọ li ọ̀pọlọpọ jù eyi lọ.
10 Nigbana li Amasiah yà wọn, ani
ẹgbẹ-ogun ti o ti tọ̀ ọ lati Efraimu wá, lati
tun pada lọ ile wọn: ibinu wọn si ru gidi-
gidi si Juda, nwọn si pada si ile wọn ni
irunu.
11 Amasiah si mu ara le, o si kó awọn
enia rẹ̀ jade, o si lọ si afonifoji iyọ̀, o si pa
ẹgbarun ninu awọn ọmọ Seiri.
12 Ati ẹgbãrun alãye li awọn ọmọ Juda
kó ni igbekun lọ, nwọn si mu wọn lọ si
ỏke apata na, nwọn si tãri wọn silẹ lati
ỏke apata na, nwọn si fọ́ tũtu.
13 Ṣugbọn awọn ọmọ-ogun ti Amasiah
ran pada lọ, ki nwọn ki o máṣe ba on lọ si
ogun, kọlù awọn ilu Juda lati Samaria titi
de Bet-horoni, nwọn si pa ẹgbẹdogun ninu
wọn, nwọn si kó ikógun pipọ.
14 O si ṣe lẹhin ti Amasiah ti ibi pipa
awọn ara Edomu bọ̀, o si mu awọn oriṣa
awọn ọmọ Seiri bọ̀, o si gà wọn li oriṣa
fun ara rẹ̀, o si tẹ̀ ara rẹ̀ ba niwaju wọn, o
si sun turari fun wọn.
15 Nitorina ni ibinu Oluwa ru si Ama-
siah o si ran woli kan si i, ti o wi fun u
pe, Eṣe ti iwọ fi nwá oriṣa awọn enia na, ti
kò le gbà awọn enia wọn lọwọ rẹ?
16 O si ṣe bi o ti mba a sọ̀rọ, ọba si wi
fun u pe, A ha fi ọ ṣe igbimọ̀ ọba bi? fi
mọ: ẽṣe ti a o fi pa ọ? Nigbana ni woli
na fi mọ; o si wipe, Emi mọ̀ pe, Ọlọrun ti
pinnu rẹ̀ lati pa ọ run, nitoriti iwọ ti ṣe
eyi, ti iwọ kò si tẹ eti si imọ̀ran mi.
17 Nigbana ni Amasiah, ọba Juda, gbà
ẹ̀kọ, o si ranṣẹ si Joaṣi ọmọ Jehoahasi, ọmọ
Jehu ọba Israeli, wipe, Wá, jẹ ki a wò ara
wa li oju.
18 Joaṣi, ọba Israeli, si ranṣẹ si Amasiah,
ọba Juda, wipe, Ẹgun-ọ̀gan ti o wà ni
Lebanoni ranṣẹ si igi kedari ti o wà ni
Lebanoni, wipe, Fi ọmọbirin rẹ fun ọmọ
mi li aya: ẹranko igbẹ kan ti o wà ni
Lebanoni si kọja nibẹ, o si tẹ ẹ̀gun-ọ̀gan na
mọlẹ.
19 Iwọ wipe, kiyesi i, iwọ ti pa awọn
ara Edomu; ọkàn rẹ si gbé soke lati ma
ṣogo: njẹ gbe ile rẹ, ẽṣe ti iwọ nfiran fun
ifarapa rẹ, ti iwọ o fi ṣubu, ani iwọ ati Juda
pẹlu rẹ?
20 Ṣugbọn Amasiah, kò fẹ igbọ́; nitori

Digitized by Google

lati ọdọ Ọlọrun wá ni, ki o le fi wọn le
awọn ọta wọn lọwọ, nitoriti nwọn nwá
awọn oriṣa Edomu.
21 Bẽni Joaṣi, ọba Israeli gòke lọ; nwọn
si wò ara wọn li oju, on ati Amasiah, ọba
Juda, ni Bet-Ṣemeṣi ti iṣe ti Juda,
22 A si ṣẹ́ Juda niwaju Israeli, nwọn
salọ olukuluku sinu agọ rẹ̀.
23 Joaṣi ọba Israeli si mu Amasiah, ọba
Juda ọmọ Joaṣi, ọmọ Ahasiah ni Bet-
Ṣemeṣi, o si mu u wá si Jerusalemu, o si
wó odi Jerusalemu lati ẹnu-bode Efraimu
titi de ẹnu-bode igun, irinwo igbọnwọ.
24 O si mu gbogbo wura ati fadakà, ati
gbogbo ohun-elo ti a ri ni ile Ọlọrun lọdọ
Obed-Edomu, ati awọn iṣura ile ọba, ati
awọn ògo pẹlu, o si pada lọ si Samaria.
25 Amasiah, ọmọ Joaṣi, ọba Juda, wà li
ãye lẹhin ikú Joaṣi, ọmọ Jehoahasi ọba
Israeli, li ọdun mẹdogun.
26 Ati iyokù iṣe Amasiah, ti iṣaju ati ti
ikẹhin, kiyesi i, a kò ha kọ wọn sinu iwe
awọn ọba Juda ati Israeli?
27 Njẹ lẹhin àkoko ti Amasiah yipada
kuro lati má tọ̀ Oluwa lẹhin, nwọn di ọ̀tẹ
si i ni Jerusalemu; o si salọ si Lakiṣi:
ṣugbọn nwọn ranṣẹ tẹlẽ ni Lakiṣi, nwọn si
pa a nibẹ.
28 Nwọn si mu u wá lori ẹṣin, nwọn si
sin i pẹlu awọn baba rẹ̀ ni ilu Dafidi.

## ORI 26.

NIGBANA ni gbogbo enia Juda mu Us-
siah ti iṣe ẹni ọdun mẹrindilogun,
nwọn si fi i jọba ni ipò baba rẹ̀, Amasiah.
2 On kọ́ Elotu, o si mu u pada fun
Juda; lẹhin ti ọba sùn pẹlu awọn baba rẹ̀.
3 Ẹni ọdun mẹrindilogun ni Ussiah,
nigbati o bẹrẹ si ijọba, o si jọba ọdun
mejilelãdọta ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀
si ni Jekoliah ti Jerusalemu.
4 O si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa, gẹgẹ bi
gbogbo eyiti baba rẹ̀, Amasiah, ti ṣe.
5 O si wá Ọlọrun li ọjọ Sekariah, ẹniti
o li oye ninu iran Ọlọrun: niwọn ọjọ ti o
wá Oluwa, Ọlọrun si mu u ṣe rere.
6 O si jade lọ, o si ba awọn ara Filistia
jagun, o si wó odi Gati ati odi Jabne ati
odi Aṣdodu, o si kọ́ ilu wọnni ni Aṣdodu,
ati lãrin awọn ara Filistia.
7 Ọlọrun si ràn a lọwọ si awọn ara
Filistia, ati si awọn ara Arabia, ti ngbe ni
Gur-Baali, ati awọn ara Mehuni.
8 Awọn ara Ammoni ta Ussiah li ọrẹ:
orukọ rẹ̀ si tàn lọ kakiri titi de atiwọ
Egipti; nitoriti o mu ara rẹ̀ le gidigidi.
9 Ussiah si kọ́ ile iṣọ ni Jerusalemu, nibi
ẹnu-bode Igun, ati nibi ẹnu-bode Afonifoji,
ati nibi iṣẹpo-odi, o si mu wọn le.
10 O kọ́ ile iṣọ li aginju pẹlu, o si wà
kanga pupọ: nitoriti o li ẹran-ọsin pipọ,
ati ni ilẹ isalẹ, ati ni pẹ̀tẹlẹ: o ni àgbẹ ati
awọn olutọju àjara lori òke nla, ati lori
Karmeli: nitoriti o fẹran àgbẹ-ṣiṣe.
11 Ussiah si li ẹgbẹ́-ogun awọn enia ti
njagun, ti ima lọ ijagun, li ẹgbẹgbẹ gẹgẹ bi
iye kikà wọn, nipa ọwọ Jegieli, akọwe, ati
Maaseiah, olori labẹ ọwọ Hananiah, ọkan
ninu awọn olori ogun ọba.
12 Gbogbo iye olori awọn baba, ala-
gbara akọni ogun jẹ ẹgbẹtala.
13 Ati li ọwọ wọn li agbara ogun kan
wà, ọkẹ mẹdogun enia o le ọdẹgbãrin ti o
mura, ti nfi àgbara nla jagun, lati ràn ọba
lọwọ si ọta.
14 Ussiah si pesè fun wọn, já gbogbo
ogun na, asà ati ọ̀kọ, ati akoro, ati ohun
ihamọra-ọrùn, ati ọrun titi de okuta kàna-
kàna.
15 O si ṣe ohun ẹrọ-ijagun ni Jerusa-
lemu, ihumọ ọlọgbọ́n enia, lati wà lori ile-
iṣọ, ati lori igun odi, lati fi tafa, ati lati fi
sọ okuta nla. Orukọ rẹ̀ si tàn lọ jìnajina,
nitoriti a ṣe iranlọwọ iyanu fun u, titi o fi
li agbara.
16 Ṣugbọn nigbati o li agbara tan, ọkàn
rẹ̀ gbé ga soke si iparun; nitoriti o ṣe ire-
kọja si Oluwa Ọlọrun rẹ̀, o si lọ sinu tempili
Oluwa, lati sun turari lori pẹpẹ turari.
17 Asariah, alufa si wọle tọ̀ ọ lọ ati
ọgọrin alufa Oluwa pẹlu rẹ̀, awọn ala-
gbara,
18 Nwọn si tako Ussiah ọba, nwọn si
wi fun u pe, Ki iṣe tirẹ, Ussiah, lati sun
turari fun Oluwa, bikòṣe ti awọn alufa,
awọn ọmọ Aaroni ti a yà si mimọ́ lati sun
turari: jade kuro ni ibi mimọ́; nitoriti
iwọ ti dẹṣẹ; bẽni kì yio ṣe fun ọlá rẹ lati
ọdọ Oluwa Ọlọrun.
19 Nigbana ni Ussiah binu, awọturari
si mbẹ lọwọ rẹ̀ lati sun turari: ati nigbati
o binu si awọn alufa, ẹ̀tẹ yọ ni iwaju rẹ̀,
loju awọn alufa ni ile Oluwa lẹba pẹpẹ
turari.
20 Ati Asariah, olori alufa, ati gbogbo
awọn alufa wò o, si kiyesi i, o dẹtẹ ni
iwaju rẹ̀, nwọn si tì i jade kuro nibẹ,
nitọtọ, ontikararẹ̀ yara pẹlu lati jade, ni-
toriti Oluwa ti lù u.
21 Ussiah ọba, si di adẹ̀tẹ titi di ọjọ ikú
rẹ̀, o si ngbe ile àrun, nitori adẹ̀tẹ ni iṣe,
nitoriti a ké e kuro ninu ile Oluwa:

Digitized by Google

Jotamu, ọmọ rẹ̀, si wà lori ile ọba, o nṣe idajọ awọn enia ile na,

22 Ati iyokù iṣe Ussiah, ti iṣaju ati ti ikẹhin ni Isaiah woli, ọmọ Amosi, kọ.

23 Bẽni Ussiah sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, nwọn si sìn i pẹlu awọn baba rẹ̀ ni oko isinkú ti iṣe ti awọn ọba; nitoriti nwọn wipe, Adẹtẹ li on: Jotamu, ọmọ rẹ̀, si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 27.

ENI ọdun mẽdọgbọ̀n ni Jotamu, nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun mẹrindilogun ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ si ni Jeruṣa, ọmọbirin Sadoku.

2 O si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa, gẹgẹ bi gbogbo eyiti baba rẹ̀ Ussiah ti ṣe; kiki kò wọ inu tempili Oluwa lọ, ṣugbọn awọn enia nṣe ibi sibẹsibẹ.

3 On si kọ́ ẹnu-ọ̀na giga ile Oluwa, ati lori odi Ofeli, o kọ́ pupọ.

4 Ani o kọ́ ilu wọnni li òke Juda, ati ninu igbo, o mọ ile-odi ati ile-iṣọ.

5 O si ba ọba awọn ara Ammoni jà pẹlu, o si bori wọn. Awọn ara Ammoni si fun u li ọgọrun talenti fadakà li ọdun na, ati ẹgbãrun oṣuwọn alikama, ati ẹgbãrun ti barli. Eyi li awọn ara Ammoni san fun u, ati lọdun keji ati lọdun kẹta.

6 Bẽni Jotamu di alagbara, nitoriti o tun ọ̀na rẹ̀ ṣe niwaju Oluwa Ọlọrun rẹ̀.

7 Ati iyokù iṣe Jotamu ati gbogbo ogun rẹ̀, ati ọ̀na rẹ̀, kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe awọn ọba Israeli ati Juda.

8 Ẹni ọdun mẽdọgbọ̀n ni, nigbati o bẹ̀re si ijọba, o si jọba ọdun mẹrindilogun ni Jerusalemu.

9 Jotamu si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, nwọn si sìn i ni ilu Dafidi: Ahasi, ọmọ rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 28.

ENI ogun ọdun ni Ahasi nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun mẹrindilogun ni Jerusalemu: on kò si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa, gẹgẹ bi Dafidi baba rẹ̀:

2 Nitoriti o rìn li ọ̀na awọn ọba Israeli, o si ṣe ere didà fun Baalimu pẹlu.

3 O si sun turari li àfonifoji ọmọ Hinnomu, o si sun awọn ọmọ rẹ̀ ninu iná bi ohun-irira awọn orilẹ-ède, ti Oluwa ti le jade niwaju awọn ọmọ Israeli.

4 O si rubọ, o si sun turari ni ibi giga wọnni, ati lori òke kekere, ati labẹ gbogbo igi tutu.

5 Nitorina Oluwa Ọlọrun rẹ̀ fi i le ọba Siria lọwọ; nwọn si kọlù u, nwọn si kó ọ̀pọlọpọ ni igbekun lọ ninu wọn, nwọn si mu wọn wá si Damasku. A si fi i le ọba Israeli lọwọ pẹlu, ti o pa a ni ipakupa.

6 Nitoriti Peka, ọmọ Remaliah, pa ọkẹ mẹfa enia ni Juda ni ijọ kan, gbogbo awọn ọmọ-ogun; nitoriti nwọn ti kọ̀ Oluwa, Ọlọrun awọn baba wọn silẹ.

7 Ati Sikri, alagbara kan ni Efraimu, pa Maaseiah, ọmọ ọba, ati Asrikamu, olori ile, ati Elkana, ibikeji ọba.

8 Awọn ọmọ Israeli si kó ọkẹ mẹwa ninu awọn arakọnrin wọn ni igbekun lọ, awọn obirin, awọn ọmọkọnrin, ati awọn ọmọbirin, nwọn si kó ikogun pupọ lọdọ wọn pẹlu, nwọn si mu ikogun na wá si Samaria.

9 Woli Oluwa kan si wà nibẹ, orukọ ẹniti ijẹ Odedi: o si jade lọ ipade ogun ti o wá si Samaria, o si wi fun wọn pe, Kiyesi i, nitoriti Oluwa Ọlọrun awọn baba nyin binu si Juda li on ṣe fi wọn le nyin lọwọ, ẹnyin si pa wọn ni ipa-oró ti o de òke ọrun.

10 Ati nisisiyi ẹnyin npete lati tẹ awọn ọmọ Juda ati Jerusalemu ba fun ẹrú-kọnrin ati ẹrú-birin nyin: ẹnyin kò ha jẹbi Oluwa Ọlọrun nyin, ani ẹnyin?

11 Njẹ nitorina, ẹ gbọ́ temi, ki ẹ si jọwọ awọn igbekun ti ẹnyin ti kó ni igbekun ninu awọn arakọnrin nyin lọwọ lọ: nitori ibinu kikan Oluwa mbẹ lori nyin.

12 Nigbana li awọn kan ninu awọn olori, awọn ọmọ Efraimu, Asariah, ọmọ Johanani, Berekiah, ọmọ Meṣillemoti, ati Jehiskiah, omọ Ṣallumu, ati Amasa, ọmọ Hadlai, dide si awọn ti o ti ogun na bọ̀.

13 Nwọn si wi fun wọn pe, Ẹnyin kò gbọdọ mu awọn igbekun nì wá ihin: nitori wò o, awa ti jẹbi niwaju Oluwa, ẹnyin npete ati fi kún ẹ̀ṣẹ ati ẹbi wa: ẹbi wa sa tobi, ibinu kikan si wà lori Israeli.

14 Bẽli awọn enia ti o hamọra fi awọn igbekun ati ikogun na silẹ niwaju awọn ijoye, ati gbogbo ijọ enia.

15 Awọn ọkọnrin ti a pè li orukọ na sì dide, nwọn si mu awọn igbekun na, nwọn si fi ikogun na wọ̀ gbogbo awọn ti o wà ni ihoho ninu wọn, nwọn si wọ̀ wọn laṣọ, nwọn si bọ̀ wọn ni bàta, nwọn si fun wọn ni ohun jijẹ ati ohun mimu, nwọn si fi ororo kùn wọn li ara, nwọn si kó gbogbo awọn alailera ninu wọn sori kẹtẹkẹtẹ, nwọn si mu wọn wá si Jeriko, ilu ọlọpẹ si ọdọ arakọnrin wọn: nigbana ni nwọn pada wá si Samaria.

16 Li akokò na ni Ahasi ọba, ranṣẹ si awọn ọba Assiria lati ràn on lọwọ.



Digitized by Google

17 Awọn ara Edomu si tun wá, nwọn si
kọlù Juda, nwọn si kó igbekun diẹ lọ.
18 Awọn ara Filistia pẹlu ti gbé ogun lọ
si ilu pẹtẹle wọnni, ati siha gusu Juda,
nwọn si ti gbà Bet-ṣemeṣi, ati Ajaloni, ati
Gederoti, ati Ṣoko pẹlu ileto rẹ̀, Timna
pẹlu ileto rẹ̀, ati Gimso pẹlu ati ileto rẹ̀:
nwọn si ngbe ilẹ.
19 Nitoriti Oluwa ti rẹ̀ Juda silẹ nitori
Ahasi, ọba Juda: nitoriti o mu Juda di
alaini iranlọwọ, o si ṣe irekọja gidigidi si
Oluwa.
20 Tilgati-pilnesari, ọba Assiria, si tọ̀
ọ wá, ọ si pọn ọ̀ loju, ṣugbọn kò fun u li
agbara.
21 Ahasi sa kó ninu ini ile Oluwa, ati
ninu ile ọba, ati ti awọn ijoye, o si fi fun
ọba Assiria: ṣugbọn kò ràn a lọwọ.
22 Ati li akokò ipọnju rẹ̀, o tun ṣe ire-
kọja si i si Oluwa. Eyi ni Ahasi, ọba.
23 Nitori ti o rubọ si awọn oriṣa Da-
masku, awọn ẹniti o kọlù u: o si wipe,
Nitoriti awọn oriṣa awọn ọba Siria ràn wọn
lọwọ, nitorina li emi o rubọ si wọn, ki
nwọn le ràn mi lọwọ. Ṣugbọn awọn na ni
iparun rẹ̀ ati ti gbogbo Israeli.
24 Ahasi si kó gbogbo ohun-elo ile Ọlọ-
run jọ, o si ké kuro lara ohun-elo ile Ọlọ-
run, o si tì ilẹkun ile Oluwa, o si tẹ́ pẹpẹ
fun ara rẹ̀ ni gbogbo igun Jerusalemu.
25 Ati ni gbogbo orori ilu Juda li o ṣe
ibi giga wọnni, lati sun turari fun awọn
ọlọrun miran, o si mu Oluwa Ọlọrun awọn
baba rẹ̀ binu.
26 Ati iyokù iṣe rẹ̀, ati ti gbogbo ọ̀na rẹ̀
ti iṣaju ati ti ikẹhin, kiyesi i, a kọ wọn
sinu iwe awọn ọba Juda ati Israeli.
27 Ahasi si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀, nwọn
si sìn i ni ilu na, ani ni Jerusalemu; ṣu-
gbọn nwọn kò mu u wá sinu awọn isa-okú
awọn ọba Israeli: Hesekiah ọmọ rẹ si jọba
ni ipọ̀ rẹ̀.

## ORI 29.

ENI ọdun mẹdọgbọn ni Hesekiah, nigbati
o bẹrẹ si ijọba, o si jọba ọdun mọ-
kandilọgbọn ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀
si ni Abijah, ọmọbirin Sekariah.
2 O si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa, gẹgẹ bi
gbogbo eyiti Dafidi, baba rẹ̀, ti ṣe.
3 Li ọdun kini ijọba rẹ̀ li oṣù kini, o ṣí
ilẹkun ile Oluwa, o si tun wọn ṣe.
4 O si mu awọn alufa wá ati awọn ọmọ
Lefi, o si kó wọn jọ si ita ila-õrun.
5 O si wi fun wọn pe, Ẹ gbọ́ temi, ẹnyin
ọmọ Lefi; ẹ yà ara nyin si mimọ́ nisisiyi,
ki ẹ si yà ile Oluwa Ọlọrun awọn baba nyin
si mimọ́, ki ẹ si kó ohun aimọ́ na jade kuro
ní ibi mimọ́.
6 Awọn baba wa sa ti dẹṣẹ, nwọn si ti
ṣe ibi li oju Oluwa Ọlọrun wa, nwọn si ti
kọ̀ ọ silẹ, nwọn si ti yi oju wọn pada kuro
ni ibugbe Oluwa, nwọn si ti pa ẹhin wọn
da.
7 Nwọn ti tì ilẹkun iloro na pẹlu, nwọn
si ti pa fitila, nwọn kò si sun turari, bẽni
nwọn kò ru ẹbọ sisun ni ibi mimọ́ si Ọlọrun
Israeli.
8 Nitorina ibinu Oluwa wà lori Juda ati
Jerusalemu, o si fi wọn fun wàhala, ati
iyanu ati ẹ̀sin, bi ẹnyin ti fi oju nyin ri.
9 Sa wò o, awọn baba wa ti ti ipa idà
ṣubu, ati awọn ọmọkọnrin wa, ati awọn
ọmọbirin wa, ati awọn obirin wa wà ni
igbekun nitori eyi.
10 Njẹ o wà li ọkàn mi lati ba Oluwa
Ọlọrun Israeli dá majẹmu, ki ibinu rẹ̀
kikan ki o le yipada kuro lọdọ wa.
11 Ẹnyin ọmọ mi, ẹ máṣe jafara nisisiyi:
nitori ti Oluwa ti yàn nyin lati duro ni-
waju rẹ̀, lati sìn i, ati ki ẹnyin ki o mã ṣe
iranṣẹ fun u, ki ẹ si mã sun turari.
12 Nigbana li awọn ọmọ Lefi dide, Ma-
hati, ọmọ Amasai, ati Joeli, ọmọ Asariah,
ninu awọn ọmọ Kohati: ati ninu awọn
ọmọ Merari, Kiṣi, ọmọ Abdi, ati Asariah,
ọmọ Jehaleeli: ati ninu awọn ọmọ Gerṣoni,
Joah, ọmọ Simma, ati Edeni, ọmọ Joah:
13 Ati ninu awọn ọmọ Elisafani, Ṣimri
ati Jegieli: ati ninu awọn ọmọ Asafu,
Sekariah ati Mattaniah.
14 Ati ninu awọn ọmọ Hemani, Jehieli
ati Ṣimei: ati ninu awọn ọmọ Jedutuni,
Ṣemaiah ati Ussieli.
15 Nwọn si kó awọn arakọnrin wọn jọ,
nwọn si yà ara wọn si mimọ́, nwọn si wá
nipa aṣẹ ọba gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, lati gbá
ile Oluwa mọ́.
16 Awọn alufa si wọ inu ile Oluwa lọhun
lọ, lati gbá a mọ́, nwọn si mu gbogbo ẽri
ti nwọn ri ninu tempili Oluwa jade si inu
agbala ile Oluwa. Awọn ọmọ Lefi si kó
o, nwọn si rù u jade gbangba lọ si odò
Kedroni.
17 Njẹ nwọn bẹrẹ li ọjọ kini oṣù kini,
lati yà a si mimọ́, ati li ọjọ kẹjọ oṣù na,
nwọn de iloro Oluwa: bẽni nwọn fi ọjọ
mẹjọ yà ile Oluwa si mimọ́; ati li ọjọ
kẹrindilogun oṣù kini na, nwọn pari rẹ̀.
18 Nigbana ni nwọn wọle tọ̀ Hesekiah
ọba, nwọn si wipe: Awa ti gbá ile Oluwa
mọ́, ati pẹpẹ ẹbọ sisun, pẹlu gbogbo ohun-

Digitized by Google

elo rẹ̀, ati tabili akara-ifihan, pẹlu gbogbo
ohun-elo rẹ̀.
19 Pẹlupẹlu gbogbo ohun-elo, ti Ahasi,
ọba, ti sọ di alaimọ́ ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, li akokò
ijọba rẹ̀, li awa ti pese ti awa si ti yà si
mimọ́, si kiyesi i, nwọn mbẹ niwaju pẹpẹ
Oluwa.
20 Nigbana ni Hesekiah, ọba, dide ni
kutukutu; o si kó awọn olori ilu jọ, o si
gòke lọ sinu ile Oluwa.
21 Nwọn si mu akọ-malu meje wá, ati
àgbo meje, ati ọdọ-agutan meje, ati obukọ
meje fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ fun ijọba na, ati fun ibi
mimọ́ na, ati fun Juda. O si paṣẹ fun
awọn alufa, awọn ọmọ Aaroni, lati fi wọn
rubọ lori pẹpẹ Oluwa.
22 Bẹ̃ni awọn alufa pa awọn akọmalu
na, nwọn si gba ẹ̀jẹ na, nwọn si fi wọ́n ara
pẹpẹ: bẹ̃ gẹgẹ nigbati nwọn pa awọn àgbo,
nwọn fi ẹ̀jẹ na wọ́n ara pẹpẹ: nwọn pa
awọn ọdọ-agutan pẹlu, nwọn si fi ẹ̀jẹ na
wọ́n ara pẹpẹ.
23 Nwọn si mu awọn òbukọ ẹbọ-ẹ̀ṣẹ wá
siwaju ọba ati ijọ enia na: nwọn si fi ọwọ
wọn le wọn lori.
24 Awọn alufa si pa wọn, nwọn si fi ẹ̀jẹ
wọn ṣe ilaja lori pẹpẹ, lati ṣe etutu fun
gbogbo Israeli; nitoriti ọba paṣẹ, ki a ṣe
ẹbọ sisun ati ẹbọ-ẹ̀ṣẹ fun gbogbo Israeli.
25 O si mu awọn ọmọ Lefi duro ninu ile
Oluwa, pẹlu kimbali, pẹlu ohun-elo orin,
ati pẹlu duru, gẹgẹ bi aṣẹ Dafidi, ati ti
Gadi, ariran ọba, ati Natani, woli, nitori
aṣẹ Oluwa ni lati ọwọ awọn woli rẹ̀.
26 Awọn ọmọ Lefi si duro pẹlu ohun-
ẹlo orin Dafidi, ati awọn alufa pẹlu ipè.
27 Hesekiah si paṣẹ lati ru ẹbọ sisun
lori pẹpẹ na. Nigbati ẹbọ sisun na si bẹ̀rẹ,
orin Oluwa bẹ̀rẹ pẹlu ipè ati pẹlu ohun-elo
orin Dafidi, ọba Israeli.
28 Gbogbo ijọ enia na si wolẹ sìn, awọn
akọrin, kọrin, ati awọn afunpè fun: gbo-
gbo wọnyi si wà bẹ̃ titi ẹbọ sisun na fi pari
tan.
29 Nigbati nwọn si ṣe ipari ẹbọ riru, ọba
ati gbogbo awọn ti o wà pẹlu rẹ̀ tẹ̀ ara wọn
ba, nwọn si sìn.
30 Pẹlupẹlu Hesekiah ọba, ati awọn
ijoye paṣẹ fun awọn ọmọ Lefi, lati fi ọ̀rọ
Dafidi ati ti Asafu ariran, kọrin iyìn si
Oluwa: nwọn si fi inu-didùn kọrin iyìn,
nwọn si tẹri wọn ba, nwọn si sìn.
31 Nigbana ni Hesekiah dahùn, o si
wipe, Nisisiyi ọwọ nyin kún fun ẹ̀bun fun
Oluwa, ẹ ṣunmọ ihin, ki ẹ si mu ẹbọ ati
ọrẹ-ọpẹ wá sinu ile Oluwa. Ijọ ẹnia si mu
ẹbọ ati ọrẹ-ọpẹ wá; ati olukuluku ti ọkàn
rẹ̀ fẹ, mu ẹbọ sisun wá.
32 Iye ẹbọ sisun, ti ijọ enia mu wá, si
jẹ ãdọrin akọ-malu, ati ọgọrun àgbo, ati
igba ọdọ-agutan: gbogbo wọnyi si ni fun
ẹbọ-sisun si Oluwa.
33 Awọn ohun ìyasi-mimọ́ si jẹ ẹgbẹta
malu, ati ẹgbẹdogun agutan.
34 Ṣugbọn awọn alufa kò to, nwọn kò
si le họ gbogbo awọn ẹran ẹbọ sisun na:
nitorina awọn arakọnrin wọn, awọn ọmọ
Lefi ràn wọn lọwọ, titi iṣẹ na fi pari, ati
titi awọn alufa iyokù fi yà ara wọn si
mimọ́: nitori awọn ọmọ Lefi ṣe olõtọ li
ọkàn jù awọn alufa lọ lati yà ara wọn si
mimọ́.
35 Ati pẹlu, awọn ẹbọ sisun papọju,
pẹlu ọra ẹbọ-alafia, pẹlu ẹbọ ohun-mimu
fun ẹbọ sisun. Bẹ̃li a si to iṣẹ-ìsin ile
Oluwa li ẹsẹsẹ.
36 Hesekiah si yọ̀, ati gbogbo enia pe,
Ọlọrun ti mura awọn enia na silẹ: nitori
li ojiji li a ṣe nkan na.

## ORI 30.

HESEKIAH si ranṣẹ si gbogbo Israeli
ati Juda, o si kọ iwe pẹlu si Efraimu
ati Manasse, ki nwọn ki o wá sinu ile
Oluwa ni Jerusalemu, lati pa ajọ irekọja
mọ́ si Oluwa, Ọlọrun Israeli.
2 Nitoriti ọba ti gbìmọ ati awọn ijoye
rẹ̀, ati gbogbo ijọ-enia ni Jerusalemu, lati
pa ajọ irekọja mọ́ li oṣù keji.
3 Nitoriti nwọn kò le pa a mọ́ li akokò
na, nitori awọn alufa kò ti iyà ara wọn si
mimọ́ to; bẹ̃li awọn enia kò ti ikó ara
wọn jọ si Jerusalemu.
4 Ọran na si tọ́ loju ọba ati loju gbogbo
ijọ-enia.
5 Bẹ̃ni nwọn fi aṣẹ kan lelẹ, lati kede
ká gbogbo Israeli, lati Beer-ṣeba ani titi
de Dani, lati wá ipa ajọ irekọja mọ́ si
Oluwa Ọlọrun Israeli ni Jerusalemu: ni-
tori nwọn kò pa a mọ́ li ọjọ pupọ gẹgẹ bi a
ti kọ ọ.
6 Bẹ̃li awọn onṣẹ ti nsare lọ pẹlu iwe
lati ọwọ ọba ati awọn ijoye rẹ̀ si gbo-
gbo Israeli ati Juda; ati gẹgẹ bi aṣẹ ọba,
wipe, Ẹnyin ọmọ Israeli, ẹ tun yipada
si Oluwa Ọlọrun Abrahamu, Isaaki, ati
Israeli, On o si yipada si awọn iyokù ninu
nyin, ti o sala kuro lowọ awọn ọba Assiria.
7 Ki ẹnyin ki o má si ṣe dabi awọn baba
nyin, ati bi awọn arakọnrin nyin, ti o dẹṣẹ
si Oluwa, Ọlọrun awọn baba wọn, nitorina
li o ṣe fi wọn fun idahoro, bi ẹnyin ti ri.

Digitized by Google

8 Nję ki ęnyin ki o máşe şe ǫlǫrùn lile,
bi awǫn baba nyin, şugbǫn ę jǫwǫ ara nyin
lǫwǫ fun Oluwa, ki ę si wǫ̀ inu ibi-mimǫ́
rę̀ lǫ, ti on ti yà si mimǫ́ titi lai: ki ę si
sìn Oluwa, Ǫlǫrun nyin, ki imuna ibinu
rę̀ ki o le yipada kuro li ǫdǫ nyin.
9 Nitori bi ęnyin ba tun yipada si Olu-
wa, awǫn arakǫnrin nyin, ati awǫn ǫmǫ
nyin, yio ri ãnu niwaju awǫn ti o kǫ́ wǫn
ni ìgbekun lǫ, ki nwǫn ki o le tun pada
wá si ilę yi: nitori Oluwa Ǫlǫrun nyin,
oniyǫ́nu ati alãnu ni, kì yio si yi oju rę̀
pada kuro lǫdǫ nyin, bi ęnyin ba pada
sǫdǫ rę̀.
10 Bę̃ li awǫn onşę na kǫja lati ilu de
ilu, ni ilę Efraimu ati Manasse titi de Se-
buluni: şugbǫn nwǫn fi wǫn ręrin ęlęya,
nwǫn si gàn wǫn.
11 Sibę omiran ninu awǫn enia Aşeri
ati Manasse ati Sebuluni rę̀ ara wǫn silę,
nwǫn si wá si Jerusalemu.
12 Ni Juda pęlu, ǫwǫ Ǫlǫrun wà lati
fun wǫn li ǫkàn kan lati pa ofin ǫba mǫ́
ati ti awǫn ijoye, nipa ǫ̀rǫ Oluwa.
13 Ǫpǫlǫpǫ enia si pejǫ ni Jerusalemu,
lati pa ajǫ akara alaiwu mǫ́ li oşu keji, ijǫ
enia nlanla.
14 Nwǫn si dide, nwǫn si kó gbogbo
pępę ti o wà ni Jerusalemu lǫ, ati gbogbo
pępę turari ni nwǫn kó lǫ, nwǫn si dà wǫn
si odò Kidroni.
15 Nigbana ni nwǫn pa ęran irekǫja na
li ǫjǫ kęrinla oşù keji: oju si tì awǫn alu-
fa ati awǫn ǫmǫ Lefi, nwǫn si yà ara wǫn
si mimǫ́, nwǫn si mu ębǫ sisun wá sinu ile
Oluwa.
16 Nwǫn si duro ni ipò wǫn, bi ètò wǫn,
gęgę bi ofin Mose, enia Ǫlǫrun: awǫn alu-
fa wǫ́n ę̀ję na, ti nwǫn gbà lǫwǫ awǫn ǫmǫ
Lefi.
17 Nitori ǫ̀pǫlǫpǫ li o wà ninu ijǫ enia
na ti kò yà ara wǫn si mimǫ́: nitorina ni
awǫn ǫmǫ Lefi şe ntǫju ati pa ęran irekǫja
fun olukuluku ęniti o şe alaimǫ́, lati yà a
si mimǫ́ si Oluwa.
18 Ǫ̀pǫlǫpǫ enia, ani ǫ̀pǫlǫpǫ ninu Efra-
imu ati Manasse, Issakari, ati Sebuluni kò
sa wę̀ ara wǫn mǫ́, sibę nwǫn ję irekǫja na,
kì işe gęgę bi a ti kǫ ǫ. Şugbǫn Hesekiah
bę̀bę fun wǫn, wipe, Oluwa, ęni-rere, da-
riji olukuluku,
19 Ti o mura ǫkàn rę̀ lati wá Ǫlǫrun,
Oluwa Ǫlǫrun awǫn baba rę̀, şugbǫn ti kì
işe nipa ìwęnumǫ́ mimǫ́.
20 Oluwa si gbǫ́ ti Hesekiah, o si mu
awǫn enia na lara dá.
21 Awǫn ǫmǫ Israeli ti a ri ni Jerusale-
mu fi ayǫ̀ nla pa ajǫ àkara alaiwu mǫ́ li ǫjǫ
meje: awǫn ǫmǫ Lefi, ati awǫn alufa yìn
Oluwa lojojumǫ, nwǫn nfi ohun-elo olohùn
goro kǫrin si Oluwa.
22 Hesekiah sǫ̀rǫ itunu fun gbogbo awǫn
ǫmǫ Lefi, ti o loye ni ìmǫ rere Oluwa: ijǫ
meje ni nwǫn fi ję àse na, nwǫn nru ębǫ
alafia, nwǫn si nfi ohùn rara dupę fun
Oluwa, Ǫlǫrun awǫn baba wǫn.
23 Gbogbo ijǫ na si gbìmǫ lati pa ǫjǫ
meje miran mǫ́: nwǫn si fi ayǫ̀ pa ǫjǫ me-
je miran mǫ́.
24 Nitori Hesekiah, ǫba Juda, ta ijǫ
enia na li ǫrę, ęgbęrun akǫ-malu, ati ǫdę-
gbãrun àgutan: ǫ̀pǫlǫpǫ ninu awǫn alufa
si yà ara wǫn si mimǫ́.
25 Gbogbo ijǫ-enia Juda pęlu awǫn alufa
ati awǫn ǫmǫ Lefi, ati gbogbo ijǫ-enia ti o
ti inu Israeli jade wá, ati awǫn àlejo ti o ti
ilę Israeli jade wá, ati awǫn ti ngbe Juda
yǫ̀.
26 Bęli ayǫ̀ nla si wà ni Jerusalemu:
nitori lati ǫjǫ Solomoni, ǫmǫ Dafidi, ǫba
Israeli, iru eyi kò sí ni Jerusalemu.
27 Nigbana li awǫn alufa, awǫn ǫmǫ
Lefi dide, nwǫn si sure fun awǫn enia na:
a si gbǫ́ ohùn wǫn, adura wǫn si gòke lǫ si
ibugbe mimǫ́ rę̀, ani si ǫrun.

## ORI 31.

NJĘ nigbati gbogbo eyi pari, gbogbo
Israeli ti a ri nibę jade lǫ si ilu Juda
wǫnni, nwǫn si fǫ́ awǫn ere tũtu, nwǫn si
bę́ igbo òrişa lulę, nwǫn si bì ibi giga wǫnni
ati awǫn pępę şubu, ninu gbogbo Juda ati
Benjamini, ni Efraimu pęlu ati Manasse,
titi nwǫn fi pa gbogbo wǫn run patapata.
Nigbana ni gbogbo awǫn ǫmǫ Israeli yipa-
da, olukuluku si ilę-ini rę̀ si ilu wǫn.
2 Hesekiah si yàn ipa awǫn alufa ati
awǫn ǫmǫ Lefi nipa ipa wǫn, olukuluku
gęgę bi işę-ìsin rę̀, awǫn alufa ati awǫn ǫmǫ
Lefi fun ębǫ sisun, ati fun ębǫ-alafia lati
şişę, ati lati dupę, ati lati ma yìn li ęnu-
ǫna ibudo Oluwa.
3 Ǫba si fi ipin lati inu ini rę̀ sapakan
fun ębǫ sisun, fun ębǫ sisun orowurǫ ati
alalę, ati ębǫ sisun ǫjǫjǫ isimi, ati fun oşù
titun, ati fun ajǫ ti a yàn, bi a ti kǫ ǫ ninu
ofin Oluwa.
4 Pęlupęlu o paşę fun awǫn enia ti ngbe
Jerusalemu lati fi ipin kan fun awǫn alufa
ati awǫn ǫmǫ Lefi, ki nwǫn ki o le di ofin
Oluwa mu şinşin.
5 Bi aşę na ti de ode, awǫn ǫmǫ Israeli

Digitized by Google

mu ọ̀pọlọpọ akọso ọkà ati ọti-waini ati ororo, ati oyin wá, ati ninu gbogbo ibisi oko; ati idamẹwa ohun gbogbo ni nwọn mu wá li ọ̀pọlọpọ.
6 Ati awọn ọmọ Israeli ati Juda, ti ngbe inu ilu Juda wọnni, awọn pẹlu mu idamẹwa malu ati agutan wá ati idamẹwa gbogbo ohun mimọ́ ti a yà si mimọ́ si Oluwa Ọlọrun wọn, nwọn si kó wọn jọ li ọ̀kiti ọ̀kiti.
7 Li oṣù kẹta, nwọn bẹ̀rẹ si ifi ipilẹ awọn ọ̀kiti lelẹ, nwọn si pari rẹ̀ li oṣù keje.
8 Nigbati Hesekiah ati awọn ijoye de, ti nwọn si ri ọ̀kiti wọnni, nwọn fi ibukún fun Oluwa, ati Israeli enia rẹ̀.
9 Hesekiah si bère lọdọ awọn alufa ati awọn ọmọ Lefi niti ọ̀kiti wọnni.
10 Asariah, olori alufa ti ile Sadoku, si da a lohùn o si wipe, lati igba ti awọn enia bẹ̀rẹ si imu ọrẹ wá sinu ile Oluwa, awa ní to lati jẹ, a si kù pupọ silẹ: Oluwa sa ti bukún awọn enia rẹ̀; eyiti o kù ni iṣura nla yi.
11 Nigbana ni Hesekiah paṣẹ lati pèse iyàrá-iṣura ni ile Ọlọrun; nwọn si pèse wọn.
12 Nwọn si mu awọn ọrẹ ati idamẹwa ati ohun ti a yà si mimọ́ wọ̀ ile wá nitõtọ: lori eyiti, Kononiah, ọmọ Lefi, nṣe olori, Ṣimei arakọnrin rẹ̀ si ni ibikeji.
13 Ati Jehieli, ati Asasiah, ati Nahati, ati Asaheli, ati Jerimoti, ati Josabadi, ati Elieli, ati Ismakiah, ati Mahati, ati Benaiah, ni awọn alabojuto labẹ ọwọ Kononiah ati Ṣimei arakọnrin rẹ̀, nipa aṣẹ Hesekiah ọba, ati Asariah, olori ile Ọlọrun.
14 Ati Kore, ọmọ Imna, ọmọ Lefi, adèna iha ila-õrun, li o wà lori awọn ọrẹ atinuwa Ọlọrun, lati pin ẹbọ ọrẹ Oluwa, ati ohun mimọ́ julọ.
15 Ati labẹ ọwọ rẹ̀ ni Edeni, ati Miniamini, ati Jeṣua, ati Ṣemaiah, Amariah, ati Ṣekaniah, ninu ilu awọn alufa, lati fun awọn arakọnrin wọn li ẹsẹsẹ, li otitọ, bi fun ẹni-nla, bẽni fun ẹni-kekere.
16 Laika awọn ọkọnrin, ti a kọ sinu iwe idile, lati ọmọ ọdun mẹta ati jù bẽ lọ, fun olukuluku wọn ti o nwọ̀ inu ile Oluwa lọ, iwọn tirẹ̀ lojojumọ, fun iṣẹ isin wọn, ninu ilana wọn, gẹgẹ bi ipa wọn;
17 Ati fun awọn alufa ti a kọ sinu iwe nipa ile baba wọn, ati awọn ọmọ Lefi, lati ẹni ogun ọdun ati jù bẽ lọ, ninu ilana wọn, nipa ipa wọn:
18 Ati fun awọn ti a kọ sinu iwe, gbogbo awọn ọmọ kekeke wọn, awọn aya wọn, ati awọn ọmọkọnrin wọn, ati awọn ọmọbirin wọn, ja gbogbo ijọ enia na: nitori ninu otitọ ni nwọn yà ara wọn si mimọ́ ninu iṣẹ mimọ́.
19 Ati fun awọn ọmọ Aaroni, awọn alufa, ti o wà li oko igberiko ilu wọn ni olukuluku ilu, awọn ọkọnrin wà nibẹ, ti a pè li orukọ, lati ma fi fun gbogbo awọn ọkọnrin ninu awọn alufa, ati fun gbogbo awọn ti a kà ni idile idile ninu awọn ọmọ Lefi.
20 Bayi ni Hesekiah si ṣe ni gbogbo Juda, o si ṣe eyiti o dara, ti o si tọ́, ti o si ṣe otitọ, niwaju Oluwa Ọlọrun rẹ̀.
21 Ati ninu gbogbo iṣẹ ti o bẹ̀rẹ ninu iṣẹ-isin ile Ọlọrun, ati ninu ofin, ati ni aṣẹ, lati wá Ọlọrun, o fi gbogbo ọkàn rẹ̀ ṣe e, o si ṣe rere.

## ORI 32.

LẸHIN ti a ti ṣe iṣẹ wọnyi lotitọ, Sennakeribu, ọba Assiria, de, o si wọ̀ inu Juda lọ, o si dótì awọn ilu olodi, o si rò lati gbà wọn fun ara rẹ̀.
2 Nigbati Hesekiah ri pe Sennakeribu de, ti o fi oju si ati ba Jerusalemu jagun,
3 O ba awọn ijoye rẹ̀ ati awọn ọkọnrin alagbara rẹ̀ gbìmọ, lati dí omi orisun wọnni, ti mbẹ lehin ilu: nwọn si ràn a lọwọ.
4 Bẽli ọ̀pọlọpọ enia kojọ pọ̀, awọn ẹniti o dí gbogbo orisun, ati odò ti nṣàn la arin ilẹ na ja, wipe, Nitori kili awọn ọba Assiria yio ṣe wá, ki nwọn ki o si ri omi pupọ̀?
5 O mu ara rẹ̀ le pẹlu, o si mọ gbogbo odi ti o ti ya, o si gbé e ga de awọn ile-iṣọ, ati odi miran lode, o si tun Millo ṣe ni ilu Dafidi, o si ṣe ọ̀kọ ati apata li ọ̀pọlọpọ.
6 O si yàn awọn balogun lori awọn enia, o si kó wọn jọ pọ̀ sọdọ rẹ̀ ni ita ẹnu-bode ilu, o si sọ̀rọ iyanju fun wọn, wipe,
7 Ẹ mu ara le, ki ẹ si ṣe onigboya, ẹ má bẹ̀ru, bẽni ki aiya ki o máṣe fò nyin nitori ọba Assiria, tabi nitori gbogbo ọ̀pọlọpọ enia ti o wà pẹlu rẹ̀; nitori awọn ti o pẹlu wa jù awọn ti o pẹlu rẹ̀ lọ:
8 Apa ẹran-ara li o pẹlu rẹ̀, ṣugbọn Oluwa Ọlọrun wa li o pẹlu wa lati ràn wa lọwọ, ati lati jà ogun wa. Awọn enia na si gbẹkẹ wọn le ọ̀rọ Hesekiah, ọba Juda.
9 Lẹhin eyi ni Sennakeribu, ọba Assiria, rán awọn iranṣẹ si Jerusalemu, (ṣugbọn on tikararẹ̀ dótì Lakiṣi, ati gbogbo ogun rẹ̀ pẹlu rẹ̀) sọdọ Hesekiah, ọba Juda ati sọdọ gbogbo Juda ti o wà ni Jerusalemu wipe,

Digitized by Google

10 Bayi ni Sennakeribu, ọba Assiria, wi
pe, Kili ẹnyin gbẹkẹle, ti ẹnyin joko ninu
odi agbara ni Jerusalemu?
11 Kò ṣepe Hesekiah ntàn nyin lati fi
ara nyin fun ikú, nipa ìyan, ati nipa ongbẹ,
o nwipe, Oluwa, Ọlọrun wa, yio gbà wa
lọwọ ọba Assiria?
12 Kò ṣepe Hesekiah kanna li o mu ibi
giga rẹ̀ wọnni kuro, ati pẹpẹ rẹ̀, ti o si paṣẹ
fun Juda ati Jerusalemu, wipe, Ki ẹnyin
ki o mã sìn niwaju pẹpẹ kan, ki ẹnyin ki o
mã sun turari lori rẹ̀?
13 Enyin kò ha mọ̀ ohun ti emi ati awọn
baba mi ti ṣe si gbogbo enia ilẹ miran?
awọn oriṣa awọn orilẹ-ède ilẹ wọnni ha le
gbà ilẹ wọn lọwọ mi rara?
14 Tani ninu gbogbo awọn oriṣa orilẹ-
ède wọnni, ti awọn baba mi parun tũtu, ti
o le gbà enia rẹ̀ lọwọ mi, ti Ọlọrun nyin
yio fi le gbà nyin lọwọ mi?
15 Njẹ nitorina, ẹ máṣe jẹ ki Hesekiah
ki o tàn nyin jẹ, bẹ̃ni ki o máṣe rọ̀ nyin bi
iru eyi, bẹ̃ni ki ẹ máṣe gbà a gbọ́: nitoriti
kò si oriṣa orilẹ-ède tabi ijọba kan ti o le
gbà enia rẹ̀ lọwọ mi, ati lọwọ awọn baba
mi: ambọtori Ọlọrun nyin ti yio fi gbà
nyin lọwọ mi?
16 Awọn iranṣẹ rẹ̀ si sọ jù bẹ̃ lọ si Oluwa
Ọlọrun, ati si iranṣẹ rẹ̀, Hesekiah.
17 O kọ iwe pẹlu lati kẹgan Oluwa,
Ọlọrun Israeli, ati lati sọ̀rọ òdi si i, wipe,
Gẹgẹ bi awọn oriṣa orilẹ-ède ilẹ miran kò
ti gbà awọn enia wọn lọwọ mi, bẹ̃li Ọlọ-
run Hesekiah kì yio gbà awọn enia rẹ̀ lọwọ
mi.
18 Nigbana ni nwọn kigbe li ohùn rara
li ède Juda si awọn enia Jerusalemu ti mbẹ
lori odi, lati dẹruba wọn, ati lati dãmu
wọn; ki nwọn ki o le kó ilu na.
19 Nwọn si sọ̀rọ òdi si Ọlọrun Jerusa-
lemu, bi ẹnipe si awọn oriṣa enia ilẹ aiye,
ti iṣe iṣẹ ọwọ enia.
20 Ati nitori eyi ni Hesekiah, ọba, ati
Isaiah woli, ọmọ Amosi, gbadura, nwọn si
kigbe si ọrun.
21 Oluwa si rán Angeli kan, ẹniti o pa
gbogbo awọn alagbara ogun, ati awọn aṣãju,
ati awọn balogun ni ibudo ọba Assiria.
Bẹ̃li o fi itiju pada si ilẹ ontikararẹ̀. Ni-
gbati o si wá sinu ile oriṣa rẹ̀, awọn ti o ti
inu ara rẹ̀ jade si fi idà pa a nibẹ.
22 Bayi li Oluwa gbà Hesekiah ati awọn
ti ngbe Jerusalemu lọwọ Sennakeribu ọba
Assiria, ati lọwọ gbogbo awọn omiran, o si
ṣọ́ wọn ni iha gbogbo.
23 Ọ̀pọlọpọ si mu ẹ̀bun fun Oluwa wá
si Jerusalemu, ati ọrẹ fun Hesekiah, ọba
Juda: a si gbé e ga loju gbogbo orilẹ-ède
lẹhin na.
24 Li ọjọ wọnni, Hesekiah ṣe aisan de
oju ikú, o si gbadura si Oluwa; O si da a
lohùn, O si fi àmi kan fun u.
25 Ṣugbọn Hesekiah kò si tun pada san
gẹgẹ bi ore ti a ṣe fun u: nitoriti ọkàn rẹ̀
gbega: nitorina ni ibinu ṣe wà lori rẹ̀, lori
Juda, ati lori Jerusalemu.
26 Ṣugbọn Hesekiah rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, niti
igberaga ọkàn rẹ̀, ati on ati awọn ti ngbe
Jerusalemu, bẹ̃ni ibinu Oluwa kò wá sori
wọn li ọjọ Hesekiah.
27 Hesekiah si li ọrọ̀ li ọ̀pọlọpọ ati ọlá:
o si ṣe ibi-iṣura fun ara rẹ̀ fun fadakà, ati
fun wura, ati fun okuta iyebiye, ati fun
turari ati fun apata, ati fun oniruru ohun-
elo iyebiye.
28 Ile-iṣura pẹlu fun ibisi ọkà, ati ọti-
waini; ati ororo; ati ile fun gbogbo oni-
ruru ẹran, ati ọgbà fun agbo-ẹran.
29 Pẹlupẹlu o ṣe ilu fun ara rẹ̀, ati agbo
agutan ati agbo malu li ọ̀pọlọpọ: nitoriti
Ọlọrun fun u li ọrọ̀ li ọ̀pọlọpọ.
30 Hesekiah kanna yi li o dí ipa-omi ti
o wà li òke Gihoni pẹlu, o si mu u wá isalẹ
tara si iha iwọ-õrun ilu Dafidi. Hesekiah
si ṣe rere ni gbogbo iṣẹ rẹ̀.
31 Ṣugbọn niti awọn ikọ̀ awọn ọmọ-alade
Babeli, ti nwọn ranṣẹ si i, lati bère ohun-
iyanu ti a ṣe ni ilẹ na, Ọlọrun fi i silẹ lati
dán a wò, ki o le mọ̀ ohun gbogbo ti o wà
li ọkàn rẹ̀.
32 Ati iyokù iṣe Hesekiah ati iṣẹ rere rẹ̀,
kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe iran Isaiah wo-
li, ọmọ Amosi, ani ninu iwe awọn ọba Juda
ati Israeli.
33 Hesekiah si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀,
nwọn si sìn i ninu iboji awọn ọmọ Dafidi:
ati gbogbo Juda ati awọn ti ngbe Jerusa-
lemu ṣe ẹyẹ fun u ni iku rẹ̀. Manasse ọmọ
rẹ̀, si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 33.

ENI ọdun mejila ni Manasse, nigbati o
bẹrẹ si ijọba, o si jọba ọdun marundi-
lọgọta ni Jerusalemu:
2 Ṣugbọn o ṣe buburu li oju Oluwa, bi
irira awọn orilẹ-ède, ti Oluwa le jade niwaju
awọn ọmọ Israeli.
3 Nitori ti o tun kọ́ ibi giga wọnni ti
Hesekiah baba rẹ̀, ti wó lulẹ, o si gbé
pẹpẹ wọnni soke fun Baalimu, o si ṣe ere
oriṣa, o si mbọ gbogbo ogun ọrun, o si nsìn
wọn.

Digitized by Google

4 O tẹ́ pẹpẹ pẹlu ni ile Oluwa, niti eyiti
Oluwa ti sọ pe; Ni Jerusalemu li orukọ
mi yio wà lailai.
5 O si tẹ́ pẹpẹ fun gbogbo ogun ọrun li
àgbala mejeji ile Oluwa.
6 O si mu ki awọn ọmọ rẹ̀ ki o kọja lãrin
iná li àfonifoji ọmọ Hinnomu: ati pẹlu o
nṣe akiyesi afọṣẹ, o si nlò alupayida, o si
nṣe ajẹ́, o si mba okú lò, ati pẹlu oṣó: o
ṣe buburu pupọ̀ li oju Oluwa lati mu u
binu.
7 O si gbé ere gbigbẹ kalẹ, ere ti o ti yá
sinu ile Ọlọrun, niti eyiti Ọlọrun ti sọ fun
Dafidi ati Solomoni, ọmọ rẹ̀, pe, Ninu ile
yi, ati ni Jerusalemu ti emi ti yàn ninu
gbogbo ẹ̀ya Israeli, li emi o fi orukọ mi si
lailai:
8 Bẽli emi kì yio ṣi ẹsẹ Israeli mọ kuro
ni ilẹ na ti emi ti yàn fun awọn baba nyin;
kiki bi nwọn ba ṣe akiyesi lati ṣe gbogbo
eyiti emi ti pa li aṣẹ fun wọn, gẹgẹ bi
gbogbo ofin ati aṣẹ ati ilana lati ọwọ Mose
wá.
9 Bẽni Manasse mu ki Juda ati awọn
ti ngbe Jerusalemu ki o yapa, ati lati ṣe
buburu jù awọn orilẹ-ède lọ, awọn ẹniti
Oluwa ti parun niwaju awọn ọmọ Israeli.
10 Oluwa si ba Manasse wi ati awọn
enia rẹ̀; ṣugbọn nwọn kò kiyesi i.
11 Nitorina li Oluwa mu awọn balogun
ogun Assiria wá ba wọn, ti nwọn fi ìwọ
mu Manasse, nwọn si de e li ẹ̀wọn, nwọn
mu u lọ si Babeli.
12 Nigbati o si wà ninu wahala, o bẹ̀
Oluwa Ọlọrun rẹ̀, o si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ gidigidi
niwaju Ọlọrun awọn baba rẹ̀,
13 O si gbadura si i: Ọlọrun si gbọ́ ẹ̀bẹ
rẹ̀, o si tun mu u pada wá si Jerusalemu
sinu ijọba rẹ̀. Nigbana ni Manasse mọ̀ pe:
Oluwa, On li Ọlọrun.
14 Njẹ lẹhin eyi, o mọ odi kan lẹhin ilu
Dafidi, niha ìwọ-õrun Gihoni, li àfonifoji,
ani li atiwọ ẹnu-bode ẹja, o si yi Ofeli ka,
o si mọ ọ ga soke gidigidi, o si fi balogun
sinu gbogbo ilu olodi Juda wọnni.
15 O si kó awọn àjeji ọlọrun ati ere kuro
ni ile Oluwa, ati gbogbo pẹpẹ ti o ti tẹ́ lori
òke ile Oluwa ati ni Jerusalemu, o si kó
wọn danu kuro ni ilu.
16 O si tun pẹpẹ Oluwa ṣe, o si ru ẹbọ
alafia ati ẹbọ ọpẹ lori rẹ̀, o si paṣẹ fun Juda
lati ma sìn Oluwa Ọlọrun Israeli.
17 Sibẹ awọn enia nṣe irubọ ni ibi giga
wọnni, kiki si Oluwa, Ọlọrun wọn nikan
ni.
18 Ati iyokù iṣe Manasse, ati adura rẹ̀
si Ọlọrun rẹ̀, ati ọ̀rọ awọn ariran ti o ba a
sọ̀rọ li orukọ Oluwa Ọlọrun Israeli, kiye si
i, o wà ninu iwe ọba Israeli.
19 Adura rẹ̀ na pẹlu, bi Ọlọrun ti gbọ́
ẹ̀bẹ rẹ̀, ati gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ati irekọja rẹ̀ ati
ibi ti o gbe kọ́ ibi giga wọnni ti o si gbé
ere-oriṣa kalẹ, ati awọn ere yiyá, ki a to rẹ̀
ẹ silẹ, kiye si i, a kọ wọn sinu iwe itan
Hosai.
20 Manasse si sùn pẹlu awọn baba rẹ̀,
nwọn si sìn i si ile on tikalarẹ̀: Amoni,
ọmọ rẹ̀, si jọba ni ipò rẹ̀.
21 Ẹni ọdun mejidilogun ni Amoni,
nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun meji
ni Jerusalemu.
22 O si ṣe eyi ti o buru li oju Oluwa, bi
Manasse, baba rẹ̀ ti ṣe, nitori Amoni rubọ
si gbogbo awọn ere yiyá, ti Manasse baba
rẹ̀ ti ṣe, o si sìn wọn:
23 Kò si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ niwaju Oluwa bi
Manasse, baba rẹ̀, ti rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ; ṣugbọn
Amoni dẹṣẹ pupọpupọ.
24 Awọn iranṣẹ rẹ̀ si di rikiṣi si i, nwọn
si pa a ni ile rẹ̀.
25 Awọn enia ilẹ na si pa gbogbo awọn
ti o ti di rikiṣi si Amoni, ọba; awọn enia
ilẹ na si fi Josiah, ọmọ rẹ̀, jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 34.

ENI ọdun mẹjọ, ni Josiah, nigbati o bẹ̀rẹ
si ijọba, o si jọba ọdun mọkanlelọ-
gbọn ni Jerusalemu.
2 O si ṣe eyiti o tọ́ li oju Oluwa, o si rìn
li ọ̀na Dafidi, baba rẹ̀, kò si yà si ọwọ ọtún
tabi si òsi.
3 Nitori li ọdun kẹjọ ijọba rẹ̀, nigbati
o si wà li ọdọmọde sibẹ, o bẹ̀rẹ si iwá
Ọlọrun Dafidi, baba rẹ̀; ati li ọdun kejila,
o bẹ̀rẹ si iwẹ̀ Juda ati Jerusalemu mọ́ kuro
ninu ibi giga wọnni, ati ere-oriṣa, ati ere
yiyá, ati ere didà.
4 Nwọn si wó pẹpẹ Baalimu lulẹ niwaju
rẹ̀; ati awọn ere-õrun ti o wà lori wọn li o
ké lule; ati awọn ere-oriṣa, ati awọn ere-
yiyá, ati awọn ere-didà, li o fọ tũtu, o sọ
wọn di ekuru, o si gbọ̀n ọ sori isa-okú
awọn ti o ti nrubọ si wọn.
5 O si sun egungun awọn alufa-oriṣa lori
pẹpẹ wọn; o si wẹ Juda ati Jerusalemu
mọ́.
6 Bẹ̃li o si ṣe ni ilu Manasse wọnni ati
ti Efraimu, ati ti Simeoni, ani titi de Naftali,
o tú ile wọn yikakiri.
7 Nigbati o si fọ́ awọn pẹpẹ ati ere-oriṣa
dilẹ, ti o si ti gún awọn ere yiyá di ẹ̀tu, ti

Digitized by Google

o si ti ké gbogbo awọn ere-õrun lulẹ ni
gbogbo ilẹ Israeli, o pada si Jerusalemu.
8 Njẹ li ọdun kejidilogun ijọba rẹ̀, ni-
gbati o ti wẹ̀ ilẹ na mọ́, ati ile na, o rán
Ṣafani, ọmọ Asaliah, ati Maaseiah, olori
ilu na, ati Joa, ọmọ Joahasi, akọwe iranti,
lati tun ile Oluwa Ọlọrun rẹ̀ ṣe.
9 Nigbati nwọn si de ọdọ Hilkiah, olori
alufa, nwọn fi owo na ti a mu wá sinu ile
Ọlọrun le e lọwọ, ti awon ọmọ Lefi, ti o
ntọju ilẹkun, ti kójọ lati ọwọ Manasse ati
Efraimu, ati lati ọdọ gbogbo awọn iyokù
Israeli, ati lati gbogbo Juda ati Benjamini:
nwọn si pada si Jerusalemu.
10 Nwọn si fi i le ọwọ awọn ti nṣiṣe na,
ti nṣe alabojuto iṣẹ ile Oluwa, nwọn si fi i
fun awọn aṣiṣẹ ti nṣiṣẹ ile Oluwa, lati tun
ile na ṣe:
11 Awọn ọlọnà ati awọn kọlekọle ni
nwọn fifun lati ra okuta gbigbẹ́, ati ìti-igi
fun isopọ̀, ati lati tẹ́ ile wọnni ti awọn ọba
Juda ti bajẹ.
12 Awọn ọkọnrin na fi otitọ ṣiṣẹ na:
awọn alabojuto wọn ni Jahati ati Obadiah,
awọn ọmọ Lefi, ninu awọn ọmọ Merari;
ati Sekariah ati Meṣullamu, ninu awọn
ọmọ Kohati, lati mu iṣẹ lọ; ati gbogbo
awọn ọmọ Lefi, ti o ni ọgbọ́n ohun-elo orin.
13 Nwọn si wà lori awọn alãru, ati awọn
alabojuto gbogbo awọn ti nṣiṣẹ, ninu ìsin-
kisin ati ninu awọn ọmọ Lefi ni akọwe, ati
olutọju ati adèna.
14 Nigbati nwọn si mu owo na ti a mu
wá sinu ile Oluwa jade wá, Hilkiah alufa,
ri iwe ofin Oluwa ti a ti ọwọ Mose kọ.
15 Hilkiah si dahùn o si wi fun Ṣafani,
akọwe, pe, Emi ri iwe ofin ninu ile Oluwa,
Hilkiah si fi iwe na le Ṣafani lọwọ.
16 Ṣafani si mu iwe na tọ̀ ọba lọ, o si
mu èsi pada fun ọba wá wipe, Gbogbo eyi
ti a fi le awọn iranṣẹ rẹ lọwọ, nwọn ṣe e.
17 Nwọn si ti kó gbogbo owo ti a ri ni
ile Oluwa jọ, nwọn si ti fi le ọwọ awọn
alabojuto, ati le ọwọ awọn ti nṣiṣẹ.
18 Nigbana ni Ṣafani, akọwe, wi fun
ọba pe, Hilkiah alufa, fun mi ni iwe kan.
Ṣafani si kà a niwaju ọba.
19 O si ṣe, nigbati ọba gbọ́ ọ̀rọ ofin na,
o si fa aṣọ rẹ̀ ya.
20 Ọba si paṣẹ fun Hilkiah ati Ahikamu,
ọmọ Ṣafani, ati Abdoni, ọmọ Mika, ati
Ṣafani, akọwe, ati Asaiah, iranṣẹ ọba, wipe,
21 Ẹ lọ, ẹ bère lọwọ Oluwa fun mi, ati
fun awọn ti o kù ni Israeli ati ni Juda,
niti ọ̀rọ iwe ti a ri: nitori titobi ni ibinu
Oluwa ti a tú jade sori wa, nitori awọn
baba wa kò pa ọ̀rọ Oluwa mọ́, lati ṣe gẹgẹ
bi gbogbo eyiti a kọ sinu iwe yi.
22 Ati Hilkiah, ati awọn ti ọba ti yàn
tọ̀ Hulda, woli obirin, lọ, aya Ṣallumu, ọmọ
Tikehati, ọmọ Hasra, olutọju aṣọ (njẹ, o
ngbe Jerusalemu, niha keji;) nwọn si ba
a sọ̀rọ na.
23 O si dá wọn lohùn pe, Bayi li Oluwa,
Ọlọrun Israeli wi, Ẹ sọ fun ọkọnrin na ti
o rán nyin si mi pe,
24 Bayi li Oluwa wi, Kiyesi i, emi o mu
ibi wá si ihinyi ati si awọn ti ngbe ibẹ na,
ani gbogbo egún ti a kọ sinu iwe ti nwọn
ti kà niwaju ọba Juda:
25 Nitoriti nwọn ti kọ̀ mi silẹ, nwọn si
ti sun turari fun awọn ọlọrun miran, ki
nwọn ki o le fi gbogbo iṣẹ ọwọ wọn mu mi
binu; nitorina li a o ṣe tú ibinu mi sori
ihinyi, a ki yio si paná rẹ̀.
26 Bi o si ṣe ti ọba Juda ni, ẹniti o rán
nyin lati bère lọwọ Oluwa, Bayi ni ki ẹnyin
ki o wi fun u, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi
niti ọ̀rọ wọnni ti iwọ ti gbọ́:
27 Nitoriti ọkàn rẹ rọ̀, ti iwọ si rẹ̀ ara
rẹ silẹ niwaju Ọlọrun, nigbati iwọ gbọ́ ọ̀rọ
rẹ̀ si ihinyi, ati si awọn ti ngbe ibẹ, ti iwọ
si rẹ̀ ara rẹ silẹ niwaju mi, ti iwọ si fa aṣọ
rẹ ya, ti iwọ si sọkun niwaju mi; ani emi
ti gbọ́ tirẹ pẹlu, li Oluwa wi.
28 Kiyesi i, emi o kó ọ jọ sọdọ awọn
baba rẹ, a o si kó ọ jọ si isa-okú rẹ li alafia,
bẹ̃ni oju rẹ ki yio ri gbogbo ibi ti emi o mu
wá si ihinyi, ati sori awọn ti ngbe ibẹ.
Bẹ̃ni nwọn mu èsi pada fun ọba wá.
29 Nigbana ni ọba ranṣẹ, nwọn si kó
gbogbo awọn àgba Juda ati Jerusalemu jọ.
30 Ọba si gòke lọ sinu ile Oluwa, ati
gbogbo ọkọnrin Juda, ati awọn ti ngbe
Jerusalemu, ati awọn alufa, ati awọn ọmọ
Lefi, ati gbogbo enia ati ẹni-nla ati ẹni-
kekere: o si kà gbogbo ọ̀rọ inu iwe majẹmu
na ti a ri ninu ile Oluwa li eti wọn.
31 Ọba si duro ni ipò rẹ̀, o si dá majẹmu
niwaju Oluwa lati ma fi gbogbo aiya ati
gbogbo ọkàn rin tọ̀ Oluwa lẹhin, ati lati pa
ofin rẹ̀ mọ́, ati ẹri rẹ̀, ati aṣẹ rẹ̀, lati ṣe ọ̀rọ
majẹmu na ti a kọ sinu iwe yi.
32 O si mu ki gbogbo awọn ti o wà ni
Jerusalemu ati Benjamini duro ninu rẹ̀,
awọn ti ngbe Jerusalemu si ṣe gẹgẹ bi ma-
jẹmu Ọlọrun, Ọlọrun awọn baba wọn.
33 Josiah si kó gbogbo ohun-irira kuro
ninu gbogbo ilu ti iṣe ti awọn ọmọ Israeli,
o si mu ki gbogbo awọn ti o wà ni Israeli
ki o sin, ani ki nwọn sin Oluwa Ọlọrun
wọn. Ati li ọjọ rẹ̀ gbogbo nwọn kò yà

Digitized by Google

kuro lati ma to Oluwa, Ọlọrun awọn baba wọn, lẹhin.

ORI 35.

JOSIAH si pa irẹkọja kan mọ́ si Oluwa ni Jerusalemu: nwọn si pa ẹran irekọja na li ọjọ kẹrinla oṣù kini.
2 O si yàn awọn alufa si iṣẹ wọn, o si gbà wọn ni iyanju si ìsin ile Oluwa.
3 O si wi fun awọn ọmọ Lefi ti nkọ́ gbogbo Israeli, ti iṣe mimọ́ si Oluwa pe, Ẹ gbé apoti-ẹri mimọ́ nì lọ sinu ile na ti Solomoni, ọmọ Dafidi, ọba Israeli ti kọ́; kì yio jẹ ẹrù li ejika mọ́: ẹ sìn Oluwa Ọlọrun nyin nisisiyi, ati Israeli, awọn enia rẹ̀;
4 Ẹ si mura nipa ile awọn baba nyin, li ẹsẹsẹ nyin, gẹgẹ bi iwe Dafidi, ọba Israeli, ati gẹgẹ bi iwe Solomoni, ọmọ rẹ̀;
5 Ẹ si duro ni ibi mimọ́ na, gẹgẹ bi ipin idile awọn baba arakọnrin nyin, awọn enia na, ati bi ipin idile awọn Lefi.
6 Bẹ̃ni ki ẹ pa ẹran irekọja na, ki ẹ si yà ara nyin si mimọ́, ki ẹ si mura fun awọn arakọnrin nyin, ki nwọn ki o le mã ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa nipa ọwọ Mose.
7 Josiah si fun awọn enia na, ni ọdọ-agutan ati ọmọ ewurẹ, lati inu agbo-ẹran, gbogbo rẹ̀ fun ẹbọ irekọja na, fun gbogbo awọn ti o wà nibẹ, iye rẹ̀ ẹgbã mẹdogun, ati ẹgbẹdogun akọmalu: lati inu ini ọba ni wọnyi.
8 Awọn ijoye rẹ̀ si fi tinutinu ta awọn enia li ọrẹ, fun awọn alufa, ati fun awọn ọmọ Lefi: Hilkiah ati Sekariah ati Jehieli, awọn olori ile Ọlọrun, si fun awọn alufa fun ẹbọ irekọja na ni ẹgbẹtala ẹran-ọ̀sin kekeke, ati ọ̃dunrun malu.
9 Koniah ati Ṣemaiah ati Netaneeli, awọn arakọnrin rẹ, ati Hasabiah ati Jehieli ati Josabadi, olori awọn ọmọ Lefi, si fun awọn ọmọ Lefi fun ẹbọ irekọja na ni ẹgbẹdọgbọn ọdọ-agutan, ati ọdẹgbẹta malu.
10 Bẹ̃li a si mura ìsin na, awọn alufa si duro ni ipò wọn, ati awọn ọmọ Lefi ni ipa iṣẹ wọn gẹgẹ bi aṣẹ ọba.
11 Awọn ọmọ Lefi si pa ẹran irekọja na, awọn alufa si wọ́n ẹ̀jẹ na lati ọwọ wọn wá, awọn ọmọ Lefi si bó wọn.
12 Nwọn si yà awọn ẹbọ-sisun sapakan, ki nwọn ki o le pin wọn funni gẹgẹ bi ipin idile awọn enia, lati rubọ si Oluwa, bi a ti kọ ọ ninu iwe Mose. Bẹ̃ni nwọn si ṣe awọn malu pelu.
13 Nwọn si fi iná sun irekọja na gẹgẹ bi ilana na: ṣugbọn awọn ẹbọ mimọ́ iyokù ni nwọn bọ̀ ninu ìkoko, ati ninu òdu ati ninu agbada, nwọn si pin i kankan fun gbogbo enia.
14 Lẹhin na nwọn mura silẹ fun ara wọn, ati fun awọn alufa; nitoriti awọn alufa, awọn ọmọ Aaroni, wà ni riru ẹbọ sisun ati ọ̀ra titi di alẹ; nitorina awọn ọmọ Lefi mura silẹ fun ara wọn ati fun awọn alufa, awọn ọmọ Aaroni.
15 Awọn akọrin, awọn ọmọ Asafu duro ni ipò wọn, gẹgẹ bi ofin Dafidi, ati ti Asafu, ati ti Hemani, ati ti Jedutuni, ariran ọba; awọn adèna si duro ni olukuluku ẹnu-ọ̀na; nwọn kò gbọdọ lọ kuro li ọ̀na-iṣẹ wọn nitoriti awọn arakọnrin wọn, awọn ọmọ Lefi, ti mura silẹ dè wọn.
16 Bẹ̃ni a si mura gbogbo ìsin Oluwa li ọjọ kanna, lati pa irekọja mọ́, ati lati ru ẹbọ sisun lori pẹpẹ Oluwa, gẹgẹ bi ofin Josiah, ọba.
17 Ati awọn ọmọ Israeli ti a ri nibẹ, pa irekọja na mọ́ li akoko na, ati ajọ aiwukara li ọjọ meje.
18 Kò si si irekọja kan ti o dabi rẹ̀ ti a ṣe ni Israeli lati igba ọjọ Samueli woli; bẹ̃ni gbogbo awọn ọba Israeli kò pa iru irekọja bẹ̃ mọ́, bi eyi ti Josiah ṣe, ati awọn alufa, ati awọn ọmọ Lefi, ati gbogbo Juda ati Israeli ti a ri nibe, ati awọn ti ngbe Jerusalemu.
19 Li ọdun kejidilogun ijọba Josiah li a pa irekọja yi mọ́.
20 Lẹhin gbogbo eyi, ti Josiah ti tun ile na ṣe tan, Neko, ọba Epipti, gòke wá, si Karkemiṣi lẹba odò Ferate: Josiah si jade tọ̀ ọ.
21 Ṣugbọn o rán ikọ̀ si i, wipe, Kini ṣe temi tirẹ, iwọ ọba Juda? Emi kò tọ̀ ọ wá loni, bikòṣe si ile ti mo ba ni ijà: Ọlọrun sa pa aṣẹ fun mi lati yara: kuro lọdọ Ọlọrun, ẹniti o wà pẹlu mi, ki on má ba pa ọ run.
22 Ṣugbọn Josiah kò yi oju rẹ̀ pada kuro lọdọ rẹ̀, ṣugbọn o pa aṣọ ara rẹ dà, ki o le ba a jà, kò si fi eti si ọ̀rọ Neko lati ẹnu Ọlọrun wá, a si wá ijagun li àfonifoji Megiddo.
23 Awọn tafatafa si ta Josiah ọba: ọba si wi fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe, Ẹ gbé mi kuro; nitoriti mo gbà ọgbẹ gidigidi.
24 Nitorina awọn iranṣẹ rẹ̀ gbé e kuro ninu kẹkẹ́ na, nwọn si fi i sinu kẹkẹ́ rẹ̀ keji; nwọn si mu u wá si Jerusalemu, o si kú, a si sìn i ninu ọkan ninu awọn iboji awọn baba rẹ̀. Gbogbo Juda ati Jerusalemu si ṣọ̀fọ Josiah.



Digitized by Google

25 Jeremiah si pohùn rere ẹkún fun Josiah, ati gbogbo awọn akọrin ọkọnrin, ati awọn akọrin obirin, si nsọ ti Josiah ninu orin-ẹkún wọn titi di oni yi, nwọn si sọ wọn di àṣa kan ni Israeli; si kiyesi i, a kọ wọn ninu awọn orin-ẹkún.

26 Ati iyokù iṣe Josiah, ati ìwa rere rẹ̀, gẹgẹ bi eyiti a ti kọ ninu ofin Oluwa.

27 Ati iṣe rẹ̀, ti iṣaju ati ti ikẹhin, kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe awọn ọba Israeli, ati Juda.

## ORI 36.

NIGBANA ni awọn enia ilẹ na mu Jehoahasi, ọmọ Josiah, nwọn si fi i jọba ni ipò baba rẹ̀ ni Jerusalemu.

2 Ẹni ọdun mẹtalelogun ni Jehoahasi, nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba oṣu mẹta ni Jerusalemu.

3 Ọba Egipti si mu u kuro ni Jerusalemu, o si bù ọgọrun fadakà ati talenti wura kan fun ilẹ na.

4 Ọba Egipti si fi Eliakimu, arakọnrin rẹ̀, jọba lori Juda ati Jerusalemu, o si pa orukọ rẹ̀ dà si Jehoiakimu; Neko si mu Jehoahasi, arakọnrin rẹ̀, o si mu u lọ si Egipti.

5 Ẹni ọdun mẹdọgbọn ni Jehoiakimu, nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si joba ọdun mọkanla ni Jerusalemu; o si ṣe eyi ti o buru li oju Oluwa Ọlọrun rẹ̀,

6 Nebukadnessari, ọba Babeli, gòke wá, o si dè e ni ẹ̀wọn, lati mu u lọ si Babeli.

7 Nebukadnessari kó ninu ohun-elo ile Oluwa lọ si Babeli pẹlu, o si fi wọn sinu ãfin rẹ̀ ni Babeli.

8 Ati iyokù iṣe Jehoiakimu ati awọn ohun-irira rẹ̀ ti o ti ṣe, ti a si ri ninu rẹ̀, kiyesi i, a kọ wọn sinu iwe awọn ọba Israeli ati Juda: Jehoiakini, ọmọ rẹ̀, si jọba ni ipò rẹ̀.

9 Ẹni ọdun mejidilogun ni Jehoiakini nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba oṣù mẹta ati ijọ mẹwa ni Jerusalemu: o si ṣe eyiti o buru li oju Oluwa.

10 Ati li amọdun, Nebukadnessari ranṣẹ, a si mu u wá si Babeli, pẹlu ohunelo daradara ile Oluwa, o si fi Sedekiah, arakọnrin rẹ̀, joba lori Juda ati Jerusalemu.

11 Ẹni ọdun mọkanlelogun in Sedekiah, nigbati o bẹ̀rẹ si ijọba, o si jọba ọdun mọkanla ni Jerusalemu.

12 O si ṣe eyi ti o buru li oju Oluwa Ọlọrun rẹ̀, kò si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ niwaju Jeremiah woli, ti o sọ̀rọ lati ẹnu Oluwa wa.

13 On pẹlu si ṣọ̀tẹ si Nebukadnessari ọba, ẹniti o ti mu u fi Ọlọrun bura; ṣugbọn o wà ọrùn rẹ̀ kì, o si mu aiya rẹ̀ le lati má yipada si Oluwa Ọlọrun Israeli.

14 Pẹlupẹlu, gbogbo awọn olori awọn alufa ati awọn enia dẹṣẹ gidigidi bi gbogbo irira awọn orilẹ-ède, nwọn si sọ ile Oluwa di ẽri, ti on ti yà si mimọ́ ni Jerusalemu.

15 Oluwa Ọlọrun awọn baba wọn si ranṣẹ si wọn lati ọwọ awọn onṣẹ rẹ̀, o ndide ni kùtukutu o si nranṣẹ, nitori ti o ni iyọ́nu si awọn enia rẹ̀, ati si ibugbe rẹ̀.

16 Ṣugbọn nwọn fi awọn onṣẹ Ọlọrun ṣe ẹlẹya, nwọn si kẹgan ọ̀rọ rẹ̀, nwọn si fi awọn woli rẹ̀ ṣẹsin, titi ibinu Oluwa fi ru si awọn enia rẹ̀, ti kò fi si atunṣe.

17 Nitorina li o ṣe mu ọba awọn ara Kaldea wá ba wọn, ẹniti o fi idà pa awọn ọdọmọkọnrin wọn ni ile ibi-mimọ́ wọn, kò si ni iyọ́nu si ọdọmọ́kọnrin tabi wundia, arugbo, tabi ẹniti o bà fun ogbó: on fi gbogbo wọn le e li ọwọ.

18 Ati gbogbo ohun-elo ile Ọlọrun, nla ati kekere, ati iṣura ile Oluwa ati iṣura ọba, ati ti awọn ijoye rẹ̀; gbogbo wọn li o mu wá si Babeli.

19 Nwọn si kun ile Ọlọrun, nwọn si wó odi Jerusalemu palẹ, nwọn si fi iná sun ãfin rẹ̀, nwọn si fọ́ gbogbo ohun-elo daradara rẹ̀ tũtu.

20 Awọn ti o ṣikù lọwọ idà li o kó lọ si Babeli; nibiti nwọn jẹ́ iranṣẹ fun u, ati fun awọn ọmọ rẹ̀ titi di ijọba awọn ara Persia:

21 Lati mu ọ̀rọ Oluwa ṣẹ lati ẹnu Jeremiah wá, titi ilẹ na yio fi san ọdun isimi rẹ̀; ani ni gbogbo ọjọ idahoro on nṣe isimi titi ãdọrin ọdun yio fi pé.

22 Li ọdun kini Kirusi, ọba Persia, ki ọ̀rọ Oluwa lati ẹnu Jeremiah wá ki o le ṣẹ, Oluwa ru ẹmi Kirusi, ọba Persia, soke, ti o si ṣe ikede ni gbogbo ijọba rẹ̀, o si kọ iwe pẹlu, wipe,

23 Bayi ni Kirusi, ọba Persia, wi pe, Gbogbo ijọba aiye li Oluwa Ọlọrun fi fun mi, o si ti paṣẹ fun mi lati kọ́ ile kan fun on ni Jerusalemu, ti mbẹ ni Juda. Tani ninu nyin ninu gbogbo awọn enia-rẹ̀? Oluwa Ọlọrun rẹ̀ ki o pẹlu rẹ̀, ki o si gòke lọ.

Digitized by Google

# EZRA.

## ORI 1.

LI ọdun ekini Kirusi, ọba Persia, ki ọ̀rọ
OLUWA lati ẹnu Jeremiah wá ki o le
ṣẹ, OLUWA rú ẹmi Kirusi, ọba Persia soke,
ti o mu ki a kede yi gbogbo ijọba rẹ̀ ka, a
si kọwe rẹ̀ pẹlu wipe,
2 Bayi ni Kirusi ọba Persia wi, pe OLU-
WA, Ọlọrun ọrun, ti fi gbogbo ijọba aiye
fun mi; o si ti pa a li aṣẹ lati kọ ile fun on
ni Jerusalemu ti o wà ni Juda.
3 Tani ninu nyin ninu gbogbo enia rẹ̀?
ki Ọlọrun rẹ̀ ki o wà pẹlu rẹ̀, ki o si goke
lọ si Jerusalemu, ti o wà ni Juda, ki o si
kọ ile OLUWA Ọlọrun Israeli, on li Ọlọrun,
ti o wà ni Jerusalemu.
4 Ati ẹnikẹni ti o kù lati ibikibi ti o ti
ngbe, ki awọn enia ibugbe rẹ̀ ki o fi fadaka
ràn a lọwọ, pẹlu wura, ati pẹlu ẹrù, ati pẹlu
ẹran-ọ̀sin, pẹlu ọrẹ atinuwa fun ile Ọlọrun
ti o wà ni Jerusalemu.
5 Nigbana ni awọn olori awọn baba Juda
ati Benjamini dide, ati awọn alufa, ati awọn
ọmọ Lefi, pẹlu gbogbo awọn ẹniti Ọlọrun
rú ẹmi wọn soke, lati goke lọ, lati kọ́ ile
OLUWA ti o wà ni Jerusalemu.
6 Gbogbo awọn ti o wà li agbegbe wọn
si fi ohunèlo fadaka ràn wọn lọwọ, pẹlu
wura, pẹlu ẹrù ati pẹlu ẹran-ọ̀sin, ati pẹlu
ohun iyebiye, li aika gbogbo ọrẹ atinuwa.
7 Kirusi ọba si ko ohunèlo ile OLUWA
jade, ti Nebukadnessari ti ko jade lọ lati
Jerusalemu, ti o si fi sinu ile ọlọrun rẹ̀;
8 Kirusi ọba Persia si ko wọnyi jade nipa
ọwọ Mitredati, oluṣọ iṣura, o si ka iye wọn
fun Ṣeṣbassari (Serubbabeli) bãlẹ Juda.
9 Iye wọn si li eyi: ọgbọn awo-pọ̀kọ
wura, ẹgbẹrun awo-pọ̀kọ fadaka, ọbẹ mọ-
kandilọgbọn.
10 Ọgbọn ago wura, ago fadaka iru ekeji,
irinwo o le mẹwa, ohunèlo miran si jẹ
ẹgbẹrun.
11 Gbogbo ohunèlo wura ati ti fadaka jẹ
ẹgbẹtadilọgbọn. Gbogbo wọnyi ni Ṣeṣbas-
sari mu goke wá pẹlu awọn igbekun ti a
mu goke lati Babiloni wá si Jerusalemu.

## ORI 2.

WỌNYI li awọn ọmọ igberiko Juda ti o
goke wa, lati inu igbèkun awọn ti a
ti ko lọ, ti Nebukadnessari, ọba Babiloni,
ti ko lọ si Babiloni, ti nwọn si pada wá si
Jerusalemu ati Juda, olukuluku si ilu rẹ̀:
2 Awọn ti o ba Serubbabeli wá, Jeṣua
Nehemiah, Seraiah, Reelaiah, Mordekai,
Bilṣani, Mispari, Bigfai, Rehumu, Baana.
Iye awọn ọkọnrin ninu awọn enia Israeli:
3 Awọn ọmọ Paroṣi, ọgbọkanla o din
mejidilọgbọn.
4 Awọn ọmọ Ṣefatiah, irinwo o din me-
jidilọgbọn.
5 Awọn ọmọ Ara, ẹgbẹrin o din mẹ̃dọ-
gbọn.
6 Awọn ọmọ Pahati-Moabu ninu awọn
ọmọ Jeṣua, ati Joabu, egbẹrinla o le mejila,
7 Awọn ọmọ Elamu, adọtalelẹgbẹfa o le
mẹrin.
8 Awọn ọmọ Sattu, ọtadilẹgbẹrun, o le
marun.
9 Awọn ọmọ Sakkai, ojidilẹgbẹrin.
10 Awọn ọmọ Bani, ojilelẹgbẹta, o le
meji.
11 Awọn ọmọ Bebai, ẹgbẹta o le mẹta-
lelogun.
12 Awọn ọmọ Asgadi, ẹgbẹfa, o le me-
jilelogun.
13 Awọn ọmọ Adonikami ọtalelẹgbẹta o
le mọkanlelogun.
14 Awọn ọmọ Bigfai, ẹgbã o le mẹrindi-
lọgọta.
15 Awọn ọmọ Adini, adọtalenirinwo o le
mẹrin.
16 Awọn ọmọ Ateri ti Hesekiah, meji-
dilọgọrun.
17 Awọn ọmọ Besai, ọrindinirinwo o le
mẹta.
18 Awọn ọmọ Jora, mejilelãdọfa.
19 Awọn ọmọ Haṣumu igba o le mẹta-
lelogun.
20 Awọn ọmọ Gibbari, marundilọgọrun.
21 Awọn ọmọ Betlehemu, mẹtalelọgọfa.
22 Awọn enia Netofa, mẹrindilọgọta.
23 Awọn enia Anatotu, mejidilãdọje.
24 Awọn ọmọ Asmafeti, mejilelogoji.

Digitized by Google

25 Awọn ọmọ Kirjat-arimu, Kefira ati Beeroti ọtadilẹgbẹrin o le mẹta.
26 Awọn ọmọ Rama ati Gaba, ẹgbẹta o le mọkanlelogun.
27 Awọn ọmọ Mikmasi, mejilelọgọfa.
28 Awọn enia Beteli ati Ai, igba o le mẹtalelogun.
29 Awọn ọmọ Nebo, mejilelãdọta.
30 Awọn ọmọ Magbiṣi mẹrindilọgọjọ.
31 Awọn ọmọ Elamu ekeji, ãdọtalelẹgbẹfa o le mẹrin.
32 Awọn ọmọ Harimu, ọrindinirinwo.
33 Awọn ọmọ Lodi, Hadidi ati Ono, ọrindilẹgbẹrin o le marun.
34 Awọn ọmọ Jeriko, ọtadinirinwo o le marun.
35 Awọn ọmọ Sanaa, egbejidilogun o le ọgbọn.
36 Awọn alufa; awọn ọmọ Jedaiah, ti idile Jeṣua, ogúndilẹgbẹrun o din meje.
37 Awọn ọmọ Immeri, ãdọtalelẹgbẹrun o le meji.
38 Awọn ọmọ Paṣuri, ojilelẹgbẹfa o le meje.
39 Awọn ọmọ Harimu, ẹgbẹrun o le mẹtadilogun.
40 Awọn ọmọ Lefi: awọn ọmọ Jeṣua ati Kadmieli ti awọn ọmọ Hodafiah, mẹrinlelãdọrin.
41 Awọn akọrin: awọn ọmọ Asafu, mejidilãdoje.
42 Awọn ọmọ awọn adena: awọn ọmọ Ṣalumu, awọn ọmọ Ateri, awọn ọmọ Talmoni, awọn ọmọ Akkubu, awọn ọmọ Hatita, awọn ọmọ Ṣobai, gbogbo wọn jẹ, mọkandilogoje.
43 Awọn Netinimu: awọn ọmọ Siha, awọn ọmọ Hasufa, awọn ọmọ Tabbaoti.
44 Awọn ọmọ Kerosi, awọn ọmọ Siha, awọn ọmọ Padoni.
45 Awọn ọmọ Lebana, awọn ọmọ Hagaba, awọn ọmọ Akkubu,
46 Awọn ọmọ Hagabu, awọn ọmọ Ṣalmai, awọn ọmọ Hanani;
47 Awọn ọmọ Giddeli, awọn ọmọ Gahari, awọn ọmọ Reaiah,
48 Awọn ọmọ Resini, awọn ọmọ Nekoda, awọn ọmọ Gassamu,
49 Awọn ọmọ Ussa, awọn ọmọ Pasea, awọn ọmọ Besai,
50 Awọn ọmọ Asna, awọn ọmọ Mehunimi, awọn ọmọ Nefusimi,
51 Awọn ọmọ Bakbuki, awọn ọmọ Hakufa, awọn ọmọ Har-huri,
52 Awọn ọmọ Basluti, awọn ọmọ Mehida, awọn ọmọ Harṣa,
53 Awọn ọmọ Barkosi, awọn ọmọ Sisera, awọn ọmọ Tama,
54 Awọn ọmọ Nesia, awọn ọmọ Hatifa,
55 Awọn ọmọ awọn iranṣẹ Solomoni: awọn ọmọ Sotai, awọn ọmọ Sofereti, awọn ọmọ Peruda,
56 Awọn ọmọ Jaala, awọn ọmọ Darkoni, awọn ọmọ Giddeli,
57 Awọn ọmọ Ṣefatiah, awọn ọmọ Hattili, awọn ọmọ Pokereti ti Sebaimu, awọn ọmọ Ami.
58 Gbogbo awọn Netinimu, ati awọn ọmọ awọn iranṣẹ Solomoni, jẹ irinwo o din mẹjọ.
59 Awọn wọnyi li o si goke wá lati Telmela, Telkarsa, Kerubu, Addani, ati Immeri: ṣugbọn nwọn kò le fi idile baba wọn hàn, ati iru-ọmọ wọn, bi ti inu Israeli ni awọn iṣe:
60 Awọn ọmọ Delaiah, awọn ọmọ Tobiah, awọn ọmọ Nekoda ãdọtalelẹgbẹta o le meji.
61 Ati ninu awọn ọmọ awọn alufa: awọn ọmọ Habaiah, awọn ọmọ Hakosi, awọn ọmọ Barsillai, ti o fẹ ọkan ninu awọn ọmọ Barsillai obirin, ara Gileadi li aya, a si pè e nipa orukọ wọn;
62 Awọn wọnyi li o wá iwe itan wọn ninu awọn ti a ṣiro nipa itan idile, ṣugbọn a kò ri wọn, nitori na li a ṣe yọ wọn kuro ninu oye alufa.
63 Balẹ si wi fun wọn pe, ki nwọn ki o má jẹ ninu ohun mimọ julọ, titi alufa kan yio fi dide pẹlu Urimu ati pẹlu Tummimu.
64 Apapọ gbogbo ijọ na, jẹ ẹgbã mọkanlelogun o le ojidinirinwo.
65 Li aiką iranṣẹkọnrin wọn ati iranṣẹbirin wọn, ti o jẹ ẹgbẹrindilẹgbãrin o din mẹtalelọgọta: igba akọrin ọkọnrin ati akọrin obirin li o si wà ninu wọn.
66 Ẹṣin wọn jẹ, ọtadilẹgbẹrin o din mẹrin; ibaka wọn, ojilugba o le marun.
67 Ibakasiẹ wọn, irinwo o le marundilogoji; kẹtẹkẹtẹ wọn, ẹgbẹrinlelọgbọn o din ọgọrin.
68 Ati ninu awọn olori awọn baba, nigbati nwọn de ile Oluwa ti o wà ni Jerusalemu, nwọn si ta ọrẹ atinuwa fun ile Ọlọrun, lati gbe e duro ni ipò rẹ.
69 Nwọn fi sinu iṣura iṣẹ na gẹgẹ bi agbara wọn, ọkẹ mẹta iwọn dramu wura, o le ẹgbẹrun, ẹgbẹdọgbọn mina fadaka, ati ọgọrun ẹwu alufa.
70 Bẹli awọn alufa, ati awọn ọmọ Lefi, ati omiran ninu awọn enia, ati awọn akọrin, ati awọn adèna, ati awọn Netinimu ngbe ilu wọn, gbogbo Israeli si ngbe ilu wọn.

Digitized by Google

## ORI 3.

·BATI ọsu keje si pé, ti awọn ọmọ
Israeli si wà ninu ilu wọnni, awọn
na ko ara wọn jọ pọ̀ bi ẹnikan si Jeru-
u.
Ieṣua ọmọ Jehosadaki si dide pẹlu
arakọnrin rẹ̀ awọn alufa, ati Serub-
i ọmọ Ṣealtieli, ati awọn arakọnrin
wọn si tẹ́ pẹpẹ Ọlọrun Israeli, lati ma
ọ ọrẹ sisun lori rẹ̀, gẹgẹ bi a ti kọ ọ
ofin Mose, enia Ọlọrun.
Nwọn si gbe pẹpẹ na ka ipilẹ rẹ̀; ni-
ẹ̀ru bà wọn nitoriti awọn enia ilẹ
i. Nwọn si rú ẹbọ ọrẹ sisun si Olu-
ọrẹ ẹbọ sisun li owurọ ati li aṣalẹ.
Nwọn si pa àse agọ mọ pẹlu, gẹgẹ bi a
ọ, nwọn si rú ẹbọ sisun ojojumọ pelu
iye ti a pa li aṣẹ, gẹgẹ bi isin ojojumọ;
Lẹhin na nwọn si ru ẹbọ sisun igba-
bo ati ti oṣu titun, ati ti gbogbo ajọ
va, ti a si yà si mimọ́, ati ti olukuluku
fi tinu-tinu ru ẹbọ atinuwa si Oluwa.
Lati ọjọ ikini oṣu keje ni nwọn bẹ̀rẹ
ma rú ẹbọ sisun si Oluwa. Ṣugbọn a kò
ipilẹ tempili Oluwa lelẹ.
Nwọn si fi owo fun awọn ọmọle pẹlu,
ùn awọn gbẹna-gbẹna, pẹlu onjẹ, ati
a mimu, ati ororo, fun awọn ara Sido-
ti fun awọn ara Tire, lati mu igi keda-
Lebanoni wá si okun Joppa, gẹgẹ bi
ti nwọn gbà lati ọwọ Kirusi ọba Persia.
Li ọdun keji ti nwọn wá si ile Ọlọrun
Jerusalemu, li oṣu keji, ni Serubba-
, ọmọ Ṣealtieli, bẹ̀rẹ, ati Jeṣua ọmọ
daki, ati iyokù awọn arakọnrin wọn,
n alufa ati awọn ọmọ Lefi, ati gbogbo
n ti o ti ìgbekun jade wá si Jerusalemu,
n si yan awọn ọmọ Lefi lati ẹni-ogun
n ati jù bẹ̃ lọ lati ma tọju iṣẹ ile Oluwa.
Nigbana ni Jeṣua pẹlu awọn ọmọkọn-
rẹ̀ ati awọn arakọnrin rẹ̀, Kadmieli ati
n ọmọ rẹ̀, awọn ọmọ Juda, jumọ dide
nikanṣoṣo lati ma tọju awọn onişẹ ninu
Ọlọrun; awọn ọmọ Henadadi, pẹlu
n ọmọ wọn, ati arakọnrin wọn, awọn
ọ Lefi.
0 Nigbati awọn ọmọle si fi ipilẹ tempili
wa lelẹ, nwọn mu awọn alufa duro ninu
wọn, nwọn mu ipè lọwọ, ati awọn ọmọ
i, awọn ọmọ Asafu mu kimbali lọwọ,
i ma yìn Oluwa gẹgẹ bi ìlana Dafidi ọba
aeli.
1 Nwọn si jùmọ kọrin lẹsẹsẹ lati yìn
lati dupẹ fun Oluwa, nitoripe o ṣeun,
pe anu rẹ̀ si duro lailai lori Israeli.
Gbogbo enia si ho iho nla, nigbati nwọn
nyìn Oluwa, nitoriti a fi ipilẹ ile Oluwa
lelẹ.
12 Ṣugbọn pupọ ninu awọn alufa ati
awọn ọmọ Lefi, pẹlu awọn olori awọn baba
ti iṣe alàgba, ti nwọn ti ri ile atetekọṣe,
nwọn fi ohùn rara sọkun, nigbati a fi ipilẹ
ile yi lelẹ li oju wọn, ṣugbọn awọn pupọ si
ho iho nla fun ayọ̀:
13 Tobẹ̃ ti awọn enia kò le mọ̀ iyatọ
ariwo ayọ̀ kuro ninu ariwo ẹkun awọn enia:
ñitori awọn enia ho iho nla, a si gbọ́ ariwo
na li okere rére.

## ORI 4.

NIGBATI awọn ọta Juda ati Benjamini
gbọ́ pe, awọn ọmọ-igbekun nkọ́ tempi-
li fun Oluwa Ọlọrun Israeli;
2 Nigbana ni nwọn tọ̀ Serubbabeli wá,
ati awọn olori awọn baba, nwọn si wi fun
wọn pe, Ẹ jẹ ki awa ki o ba nyin kọle, ni-
toriti awa nṣe afẹri Ọlọrun nyin, gẹgẹ bi
ẹnyin; awa si nru ẹbọ si ọdọ rẹ̀, lati ọjọ
Esarhaddoni, ọba Assuri, ẹniti o mu wa
gòke wá ihinyi.
3 Ṣugbọn Serubbabeli, ati Jeṣua ati iyo-
kù ninu awọn olori awọn baba Israeli wi
fun wọn pe, Kì iṣe fun awa pẹlu ẹnyin, lati
jumọ kọ ile fun Ọlọrun wa; ṣugbọn awa
tikarawa ni yio jùmọ kọle fun Oluwa Ọlọ,
run Israeli gẹgẹ bi Kirusi ọba, ọba Persia,
ti paṣẹ fun wa,
4 Nigbana ni awọn enia ilẹ na mu ọwọ
awọn enia Juda rọ, nwọn si yọ wọn li ẹnu
ninu kikọle na.
5 Nwọn si bẹ̀ awọn ìgbimọ li ọ̀wẹ si wọn,
lati sọ ipinnu wọn di asan, ni gbogbo ọjọ
Kirusi, ọba Persia, ani titi di ijọba Dariu-
si, ọba Persia.
6 Ati ni ijọba Ahasuerusi, ni ibẹ̀rẹ ijọba
rẹ̀, ni nwọn kọwe ẹ̀sun lati fi awọn ara
Juda ati Jerusalemu sùn.
7 Ati li ọjọ Artasasta ni Biṣlami, Mitre-
dati, Tabeeli ati awọn ẹgbẹ rẹ̀ iyokù kọwe
si Artasasta, ọba Persia: a si kọ iwe na li
ède Siria, a si ṣe itumọ rẹ̀ li ède Siria.
8 Rehumu, adele ọba, ati Ṣimṣai, akọ-
we, kọ iwe ẹ̀sun Jerusalemu si Artasasta
ọba, bi iru eyi:
9 Nigbana ni Rehumu, adele-ọba, ati
Ṣimṣai akọwe, ati awọn ẹgbẹ wọn iyokù:
awọn ara Dina, ti Afarsatki, ti Tarpeli, ti
Afarsi, ti Arkefi, ti Babiloni, ti Susanki,
ti Dehafi ati ti Elamu,
10 Ati awọn orilẹ-ède iyokù ti Asnappe-
ri, ọlọla ati ẹni-nla, nì, kó rekọja wá, ti o

Digitized by Google

si fi wọn do si ilu Samaria, ati awọn iyokù
ti o wà ni ihahin odò, ati ẹlomiran.
11 Eyi ni atunkọ iwe na ti nwọn fi ranṣẹ
si i, ani si Artasasta ọba : Iranṣẹ rẹ, awọn
enia ihahin odò ati ẹlomiran.
12 Ki ọba ki o mọ̀ pe, awọn Ju ti o ti
ọdọ rẹ wá si ọdọ wa, nwọn de Jerusalemu,
nwọn nkọ́ ọlọtẹ ilu ati ilu buburu, nwọn si
ti fi odi rẹ̀ lelẹ, nwọn si ti so ipilẹ rẹ̀ mọra
pọ̀.
13 Ki ọba ki o mọ̀ nisisiyi pe, bi a ba
kọ ilu yi, ti a si tun odi rẹ̀ gbe soke tan,
nigbana ni nwọn kì o san owo ori, owo-
bode, ati owo odè, ati bẽni nikẹhin yio si
pa awọn ọba li ara.
14 Njẹ nisisiyi lati ãfin ọba wá li a
sa ti mbọ́ wa, kò si yẹ fun wa lati ri àbu-
kun ọba, nitorina li awa ṣe ranṣẹ lati wi
fun ọba daju ;
15 Ki a le wá inu iwe-iranti awọn baba
rẹ : bẽni iwọ o ri ninu iwe-iranti, iwọ o si
mọ̀ pe, ọlọtẹ ni ilu yi, ti o si pa awọn ọba
ati igberiko li ara, ati pe, nwọn ti ṣọtẹ ni-
nu ikanna lati atijọ wá, nitori eyi li a fi fọ
ilu na.
16 Awa mu u da ọba li oju pe, bi a ba
tun ilu yi kọ, ti a si pari odi rẹ̀ nipa ọ̀na
yi, iwọ kì o ni ipin mọ ni ihahin odò.
17 Nigbana ni ọba fi èsi ranṣẹ si Rehu-
mu, adele-ọba, ati si Ṣimṣai, akọwe, pẹlu
awọn ẹgbẹ wọn iyokù ti ngbe Samaria, ati
si awọn iyokù li oke odò : Alafia ! ati kiki
miran.
18 A kà iwe ti ẹnyin fi ranṣẹ si wa daju-
daju niwaju mi.
19 Mo si paṣẹ, a si ti wá, a si ri pe, lati
atijọ wá, ilu yi a ti ma ṣọ̀tẹ si awọn ọba,
ati pe irukerudo ati ọ̀tẹ li a ti nṣe ninu rẹ̀.
20 Pẹlupẹlu awọn ọba alagbara li o ti
wà lori Jerusalemu, awọn ti o jọba lori
gbogbo ilu oke-odò ; owo ori, owo odè, ati
owo bodè li a ti nsan fun wọn.
21 Ki ẹnyin ki o paṣẹ nisisiyi lati mu
awọn ọkọnrin wọnyi ṣiwọ, ki a má si kọ ilu
na mọ, titi aṣẹ yio fi jade lati ọdọ mi wá.
22 Ẹ kiyesi ara nyin, ki ẹnyin ki o má
jafara lati ṣe eyi : ẽṣe ti ìbajẹ yio fi ma
dàgba si ipalara awọn ọba ?
23 Njẹ nigbati a ka atunkọ iwe Arta-
sasta ọba niwaju Rehumu, ati Ṣimṣai akọ-
we, ati awọn ẹgbẹ wọn, nwọn goke lọ
kankán si Jerusalemu, si ọdọ awọn Ju,
nwọn si fi ipá pẹlu agbara mu wọn ṣiwọ.
24 Nigbana ni iṣẹ ile Ọlọrun ti o wà ni
Jerusalemu, duro. Bẹ̃li o duro titi di ọdun
keji Dariusi, oba Persia.

## ORI 5.

ṢUGBỌN awọn woli, Haggai woli, ati
Sekariah ọmọ Iddo, sọ asọtẹlẹ fun
awọn Ju ti o wà ni Juda ati Jerusalemu li
orukọ Ọlọrun Israeli.
2 Li akoko na ni Serubbabeli ọmọ Ṣe-
altieli, ati Jeṣua ọmọ Josadaki dide, nwọn
si bẹ̀rẹ si ikọ́ ile Ọlọrun ni Jerusalemu ;
awọn woli Ọlọrun si wà pẹlu wọn ti nràn
wọn lọwọ.
3 Li akoko kanna ni Tatnai, bãlẹ ni
ihahin odò, ati Ṣetar-bosnai pẹlu awọn ẹgbẹ
wọn, wá si ọdọ wọn, nwọn si wi fun wọn
bayi pe, Tani fun nyin li aṣẹ lati kọ́ ile yi,
ati lati tun odi yi ṣe ?
4 Nigbana ni awa wi fun wọn bayi, pe,
Orukọ awọn ọkọnrin ti nkọ́ ile yi ti ijẹ !
5 Ṣugbọn oju Ọlọrun wọn mbẹ li ara
awọn àgba Juda, ti nwọn kò fi le mu wọn
ṣiwọ titi ọ̀ran na fi de ọdọ Dariusi : nigba-
na ni nwọn si fi èsi pada, nipa iwe nitori
eyi.
6 Atunkọ iwe na ti Tatnai, bãlẹ ni
ihahin-odọ̀, ati Ṣetar-bosnai, ati awọn ẹgbẹ
rẹ̀ rán si Dariusi ọba : awọn ara Afarsaki
ti ihahin-odò.
7 Nwọn fi iwe ranṣẹ si i, ninu eyiti a kọ
bayi ; Si Dariusi, ọba, alafia gbogbo.
8 Ki ọba ki o mọ̀ pe, awa lọ si igberiko
Judea si ile Ọlọrun ẹniti o tobi, ti a fi oku-
ta nlanla kọ, a si tẹ igi si inu ogiri na, iṣẹ
yi nlọ siwaju kánkán, o si nṣe rere li ọwọ
wọn.
9 Nigbana ni awa bi awọn àgba wọnni
li ère, a si wi fun wọn bayi pe, Tani fun
nyin li aṣẹ lati kọ́ ile yi, ati lati mọ odi
yi ?
10 Awa si bère orukọ wọn pẹlu, lati mu
ki o da ọ li oju, ki a le kọwe orukọ awọn
enia ti iṣe olori ninu wọn.
11 Bayi ni nwọn si fi èsi fun wa wipe,
Iranṣẹ Ọlọrun ọrun on aiye li awa iṣe, awa
si nkọ́ ile ti a ti kọ́ li ọdun pupọ wọnyi
sẹhin, ti ọba nla kan ni Israeli ti kọ́, ti o si
ti pari.
12 Ṣugbọn nitoriti awọn baba wa mu
Ọlọrun ọrun binu, o fi wọn le ọwọ Nebu-
kadnessari, ọba Babiloni ti Kaldea, ẹniti o
wó ile yi palẹ, ti o si kó awọn enia na lọ si
Babiloni.
13 Ṣugbọn li ọdun ekini Kirusi ọba Ba-
biloni, Kirusi ọba na fi aṣẹ lelẹ lati kọ́ ile
Ọlọrun yi.
14 Pẹlupẹlu ohunèlo wura ati ti fàdaka
ti ile Ọlọrun ti Nebukadnessari ko lati inu

Digitized by Google

tempili ti o wà ni Jerusalemu jade, ti o si
mu lọ sinu tempili Babiloni, awọn na ni
Kirusi ọba ko lati inu tempili Babiloni
jade, a si fi wọn le ẹnikan lọwọ, orukọ ẹniti
ijẹ Ṣeşbassari, ẹniti on fi jẹ bãlẹ ;
15 On si wi fun u pe, Kó ohun èlo wọnyi
lọ, ki o fi wọn si inu tempili ti o wà ni
Jerusalemu, ki o si mu ki a tun kọ ile
Ọlọrun yi si ipò rẹ̀.
16 Nigbana ni Ṣeşbassari na wá, o si fi
ipilẹ ile Ọlọrun ti o wà ni Jerusalemu lelẹ :
ati lati igba na ani titi di isisiyi li o ti mbẹ,
ni kikọ kò si ti ipari tan.
17 Njẹ nitorina, bi o ba wu ọba, jẹ ki a
wá inu ile işura ọba ti o wà nibẹ ni Babi-
loni, bi o ba ri bẽ, pe Kirusi ọba fi aşẹ lelẹ
lati kọ ile Ọlọrun yi ni Jerusalemu, ki ọba
ki o sọ eyi ti o fẹ fun wa nipa ọ̀ran yi.

## ORI 6.

NIGBANA ni Dariusi ọba paşẹ, a si wá
inu ile ti a ko iwe jọ si, nibiti a to
işura jọ si ni Babiloni.
2 A si ri iwe kan ni Ekbatana, ninu ilu
olodi ti o wà ni igberiko Medea, ati ninu
rẹ̀ ni iwe-iranti kan wà ti a kọ bayi :
3 Li ọdun ikini Kirusi ọba, Kirusi ọba
na paşẹ nipasẹ ile Ọlọrun ni Jerusalemu
pe, Ki a kọ́ ile na, ibi ti nwọn o ma ru
ẹbọ, ki a si fi ipilẹ rẹ̀ lelẹ şinşin, ki giga
rẹ̀ jẹ ọgọta igbọnwọ, ati ibu rẹ̀, ọgọta
igbọnwọ.
4 Ilè okuta nla mẹta, ati ilè igi titun
kan : ki a si şe inawo rẹ̀ lati inu ile ọba
wa :
5 Pẹlupẹlu ki a si kó ohun èlo wura ati
ti fàdaka ilẹ Ọlọrun pada, ti Nebukadnes-
sari ti kó lati inu tempili ti o wà ni Jeru-
salemu jade, ti o si ti ko wá si Babiloni, ki
a si ko wọn pada, ki a si mu wọn lọ si
inu tempili ti o wà ni Jerusalemu, olu-
kuluku ni ipò rẹ̀, ki a si tò wọn si inu ile
Ọlọrun.
6 Njẹ nisisiyi Tatnai, bãlẹ oke-odò, Ṣe-
tarbosnai, ati awọn ẹgbẹ nyin, awọn ara
Afarsaki, ti o wà li oke-odò, ki ẹnyin ki o
jina si ibẹ.
7 Ẹ jọ̃ işẹ ile Ọlọrun yi lọwọ, ki balẹ
awọn ara Juda, ati awọn àgba awọn ara
Juda ki nwọn kọ ile Ọlọrun yi si ipò rẹ̀.
8 Pẹlupẹlu mo paşẹ li ohun ti ẹnyin o şe
fun awọn àgba Juda wọnyi, fun kikọ ile
Ọlọrun yi : pe, ninu ẹru ọba, li ara owo-
odè oke-odò, ni ki a mã şe inawo fun awọn
enia wọnyi li aijafara, ki a máşe da wọn
duro.
9 Ati eyiti nwọn kò le şe alaini ẹgbọrọ
akọmalu, ati àgbo, pẹlu ọdọ-agutan fun ẹbọ
sisun si Ọlọrun ọrun, alikama, iyọ, ọti-
waini pẹlu ororo, gẹgẹ bi ilana awọn alufa
ti o wà ni Jerusalemu, ki a mu fun wọn li
ojojumọ laiyẹ̀ :
10 Ki nwọn ki o le ru ẹbọ olõrun didùn
si Ọlọrun ọrun, ki nwọn ki o si le ma gba-
dura fun ẹmi ọba, ati ti awọn ọmọ rẹ̀.
11 Pẹlupẹlu mo ti paşẹ pe, ẹnikẹni ti o
ba yi ọ̀rọ yi pada, ki a fa igi lulẹ li ara
ile rẹ̀, ki a si gbe e duro, ki a fi on na kọ
si ori rẹ̀, ki a si sọ ile rẹ̀ di ãtàn nitori
eyi.
12 Ki Ọlọrun ẹniti o mu ki orukọ rẹ̀ ma
gbe ibẹ, ki o pa gbogbo ọba, ati orilẹ-ède
run, ti yio da ọwọ wọn le lati şe ayipada,
ati lati pa ile Ọlọrun yi run, ti o wà ni
Jerusalemu. Emi Dariusi li o ti paşẹ, ki a
mu u şẹ li aijafara.
13 Nigbana ni Tatnai bãlẹ ni ihahin-
odò, Ṣetarbosnai, ati awọn ẹgbẹ wọn, gẹgẹ
bi eyiti Dariusi ọba ti ranşẹ, bẽni nwọn şe
li aijafara.
14 Awọn àgba Juda si kọle, nwọn si şe
rere nipa iyanju Haggai woli ati Sakaria
ọmọ Iddo. Nwọn si kọle, nwọn si pari
rẹ̀ gẹgẹ bi aşẹ Ọlọrun Israeli, ati gẹgẹ bi
aşẹ Kirusi, ati Dariusi ati Artasasta ọba
Persia.
15 A si pari ile yi li ọjọ kẹta oşu Adari,
ti işe ọdun kẹfa ijọba Dariusi ọba.
16 Awọn ọmọ Israeli, awọn alufa, ati
awọn ọmọ Lefi pẹlu awọn ọmọ ìgbekun
ìyoku şe ìyasimimọ́ ile Ọlọrun yi pẹlu
ayọ̀.
17 Ni iyasimimọ́ ile Ọlọrun yi, ni nwọn
si rubọ ọgọrun akọ-malu, igba àgbo, irinwo
ọdọ-agutan ; ati fun ẹbọ-ẹşẹ fun gbogbo
Israeli, obukọ mejila gẹgẹ bi iye awọn ẹya
Israeli :
18 Nwọn si fi awọn alufa si gẹgẹ bi ipa
wọn ati awọn ọmọ Lefi gẹgẹ bi ipa wọn, fun
isin Ọlọrun ni Jerusalemu, gẹgẹ bi a ti kọ
ọ ninu iwe Mose.
19 Awọn ọmọ igbekun si şe ajọ irekọja
li ọjọ kẹrinla oşu ekini.
20 Nitoriti awọn alufa, ati awọn ọmọ
Lefi ti wẹ̀ ara wọn mọ́ bi ẹnikan, gbogbo
wọn li o si mọ́, nwọn si pa ẹran irekọja fun
gbogbo awọn ọmọ igbekun, ati fun awọn
arakọnrin wọn, awọn alufa, ati fun awọn
tikara wọn.
21 Awọn ọmọ Israeli ti o ti inu igbekun
pada bọ̀, ati gbogbo iru awọn ti o ti ya ara
wọn si ọdọ wọn kuro ninu ẽri awọn keferi

Digitized by Google

ilẹ na, lati ma ṣe afẹri Oluwa Ọlọrun Israeli, si jẹ àse irekọja.
22 Nwọn si fi ayọ̀ ṣe ajọ aiwukara li ọjọ meje: nitoriti Oluwa ti mu wọn yọ̀, nitoriti o yi ọkàn ọba Assiria pada si ọdọ wọn, lati mu ọwọ wọn le ninu iṣẹ ile Ọlọrun, Ọlọrun Israeli.

## ORI 7.

NJẸ lẹhin nkan wọnyi, ni ijọba Artasasta ọba Persia, Esra ọmọ Seraiah, ọmọ Asariah, ọmọ Hilkiah,
2 Ọmọ Ṣallumu, ọmọ Sadoku, ọmọ Ahitubu,
3 Ọmọ Amariah, ọmọ Asariah, ọmọ Meraiotu,
4 Ọmọ Serahiah, ọmọ Ussi, ọmọ Bukki,
5 Ọmọ Abiṣua, ọmọ Finehasi, ọmọ Eleasari, ọmọ Aaroni olori alufa:
6 Esra yi li o gòke lati Babiloni wá; o si jẹ ayáwọ̀-akọwe ninu ofin Mose, ti Oluwa Ọlọrun Israeli fi fun ni: ọba si fun u li ohun gbogbo ti o bère, gẹgẹ bi ọwọ Oluwa Ọlọrun rẹ̀ ti wà lara rẹ̀.
7 Ati ninu awọn ọmọ Israeli, ati ninu awọn alufa, ati awọn ọmọ Lefi, ati awọn akọrin, ati awọn adèna, pẹlu awọn Netinimu si goke wá si Jerusalemu li ọdun keje Artasasta ọba.
8 On si wá si Jerusalemu li oṣu karun, eyi ni ọdun keje ọba.
9 Nitoripe lati ọjọ kini oṣu ekini li o bẹrẹ si igòke lati Babiloni wá, ati li ọjọ ikini oṣu karun li o de Jerusalemu, gẹgẹ bi ọwọ rere Ọlọrun rẹ̀ ti o wà lara rẹ̀.
10 Nitori Esra ti mura tan li ọkàn rẹ̀ lati ma wá ofin Oluwa, ati lati ṣe e, ati lati ma kọ́ni li ofin ati idajọ ni Israeli.
11 Eyi si ni atunkọ iwe na ti Artasasta ọba fi fun Esra alufa, akọwe, ani akọwe ọ̀rọ ofin Oluwa, ati ti aṣẹ rẹ̀ fun Israeli.
12 Artasasta, ọba awọn ọba, si Esra alufa, akọwe pipé ti ofin Ọlọrun ọrun, alafia:
13 Mo paṣẹ pe, ki gbogbo enia ninu awọn enia Israeli, ati ninu awọn alufa rẹ̀ ati awọn ọmọ Lefi, ninu ijọba mi, ẹniti o ba fẹ nipa ifẹ inu ara wọn lati gòkẹ lọ si Jerusalemu, ki nwọn ma ba ọ lọ.
14 Niwọn bi ati rán ọ lọ lati iwaju ọba lọ ati ti awọn ìgbimọ rẹ̀ mejeje, lati wadi ọ̀ran ti Juda ati Jerusalemu gẹgẹ bi ofin Ọlọrun rẹ ti mbẹ li ọwọ rẹ;
15 Ati lati ko fàdaka ati wura, ti ọba ati awọn ìgbimọ fi tinutinu fi fun Ọlọrun Israeli, ibugbe ẹniti o wà ni Jerusalemu.
16 Ati gbogbo fàdaka ati wura ti iwọ le ri ni gbogbo igberiko Babiloni, pẹlu ọrẹ atinuwa awọn enia, ati ti awọn alufa, ti iṣe ọrẹ atinuwa fun ile Ọlọrun wọn ti o wà ni Jerusalemu.
17 Ki iwọ ki o le fi owo yi rà li aijafara, akọmalu, àgbo, ọdọ-agutan, ati ọrẹ ohunjijẹ wọn ati ọrẹ ohun mimu wọn, ki o si fi wọn rubọ li ori pẹpẹ ile Ọlọrun nyin ti o wà ni Jerusalemu.
18 Ati ohunkohun ti o ba wu ọ, ati awọn arakọnrin rẹ lati fi fàdaka ati wura iyokù ṣe, eyini ni ki ẹnyin ki o ṣe gẹgẹ bi ifẹ Ọlọrun nyin.
19 Ohunèlo wọnni ti a fi fun ọ pẹlu fun ìsin ile Ọlọrun rẹ, ni ki iwọ ki o fi lelẹ niwaju Ọlọrun ni Jerusalemu.
20 Ati ohunkohun ti a ba fẹ pẹlu fun ile Ọlorun rẹ, ti iwọ o ri àye lati nawo rẹ̀, nawo rẹ̀ lati inu ile iṣura ọba wá.
21 Ati emi, ani Artasasta ọba paṣẹ fun gbogbo awọn olutọju iṣura, ti o wà li okeodò pe, ohunkohun ti Esra alufa, ti iṣe akọwe ofin Ọlọrun ọrun yio bère lọwọ nyin, ki a ṣe e li aijafara,
22 Titi de ọgọrun talenti fàdaka, ati de ọgọrun oṣuwọn alikama, ati de ọgọrun bati ọti-waini ati de ọgọrun bati ororo, ati iyọ laini iye.
23 Ohunkohun ti Ọlọrun ọrun palaṣẹ, ki a fi otitọ ṣe e fun ile Ọlọrun ọrun: ki ibinu ki o má de si ijọba ọba, ati awọn ọmọ rẹ̀.
24 Pẹlupẹlu ki ẹnyin ki o mọ̀ dajudaju pe, ẹnyin kò ni oyè lati di owo-ori, owoodè, ati owo-bodè ru gbogbo awọn alufa, ati awọn ọmọ Lefi, awọn akọrin, awọn adèna, awọn Netinimu, ati awọn iranṣẹ ninu ile Ọlọrun yi,
25 Ati iwọ, Esra, gẹgẹ bi ọgbọ́n Ọlọrun rẹ ti o wà li ọwọ rẹ, yan awọn oloyè ati onidajọ, ti nwọn o ma da ẹjọ fun gbogbo awọn enia ti o wà li oke-odò, gbogbo iru awọn ti o mọ̀ ofin Ọlọrun rẹ, ki ẹnyin ki o si ma kọ́ awọn ti kò mọ̀ wọn.
26 Ẹnikẹni ti kì o si ṣe ofin Ọlọrun rẹ, ati ofin ọba, ki a mu idajọ ṣe si i lara li aijafara, bi o ṣe si ikú ni, tabi lilé si oko, tabi kiko li ẹrù, tabi si sisọ sinu tubu.
27 Olubukun li Oluwa Ọlọrun awọn baba wa, ti o fi nkan bi iru eyi si ọkàn ọba, lati ṣe ogo si ile Oluwa ti o wà ni Jerusalemu:
28 Ti o si nàwọ anu si mi niwaju ọba ati awọn ìgbimọ rẹ̀, ati niwaju gbogbo awọn alagbara ijoye ọba: mo si ri iranlọwọ gbà gẹgẹ bi ọwọ Oluwa Ọlọrun mi ti o wà lara

Digitized by Google

, mo si ko awọn olori awọn enia jọ lati
ı Israeli jade, lati ba mi goke lọ.

ORI 8.

ỌNYI ni awọn olori ninu awọn baba
wọn, eyi ti a kọ sinu iwe itan-idile
ọn ti o ba mi goke lati Babiloni wá, ni
ba Artasasta ọba.
2 Ninu awọn ọmọ Finehasi, Gerṣomu;
ıu awọn ọmọ Itamari, Danieli: ninu
ọn ọmọ Dafidi, Hattuṣi.
3 Ninu awọn ọmọ Ṣekaniah, ti awọn
.ọ Paroṣi, Sekariah: ati pẹlu rẹ̀ li a ka
ọjọ ọkọnrin nipa iwe itan-idile.
4 Ninu awọn ọmọ Pahat-moabu; Eli-
ənai ọmọ Serahiah, ati pẹlu rẹ̀, igba
ọnrin.
5 Ninu awọn ọmọ Sekaniah; ọmọ Ja-
ieli, ati pẹlu rẹ̀, ọdunrun ọkọnrin.
6 Ninu awọn ọmọ Adini pẹlu, Ebedi
ıọ Jonatani, ati pẹlu rẹ̀, ãdọta ọkọnrin.
7 Ati ninu awọn ọmọ Elamu; Jeṣaiah
ıọ Ataliah, ati pẹlu rẹ̀, ãdọrin ọkọnrin.
8 Ati ninu awọn ọmọ Ṣefatiah; Seba-
ıh ọmọ Mikaeli, ati pẹlu rẹ̀, ọgọrin
ọnrin.
9 Ninu awọn ọmọ Joabu; Obadiah ọmọ
hieli ati pẹlu rẹ̀, ogunlugba ọkọnrin o
ı meji.
10 Ati ninu awọn ọmọ Ṣelomiti; ọmọ
ıafiah, ati pẹlu rẹ̀, ọgọjọ ọkọnrin.
11 Ati ninu awọn ọmọ Bebai; Sekariah,
ıọ Bebai, ati pẹlu rẹ̀, ọkọnrin mejidi-
bọn.
12 Ati ninu awọn ọmọ Asgadi; Jo-
nani ọmọ Hakkatani, ati pẹlu rẹ̀, ãdọfa
ọnrin.
13 Ati ninu awọn ọmọ ikẹhin Adoni-
mu, orukọ awọn ẹniti iṣe wọnyi, Elifeleti,
ieli, ati Ṣemaiah, ati pẹlu wọn, ọgọta
ọnrin.
14 Ninu awọn ọmọ Bigfai pẹlu; Uttai,
. Sabbudi, ati pelu wọn, ãdọrin ọkọnrin.
15 Mo si kó wọn jọ pọ li eti odò ti o ṣàn
Ahafa; nibẹ li a si gbe inu agọ li ọjọ
ọta: mo si wò awọn enia rere pẹlu awọn
ıfa, emi kò si ri ẹnikan ninu awọn ọmọ
fi nibẹ.
16 Nigbana ni mo ranṣẹ pè Elieseri,
ieli, Ṣemaiah, ati Elnatani ati Jaribi,
Elnatani, ati Natani, ati Sekariah, ati
əṣullamu, awọn olori pẹlu Joiaribi, ati
natani, enia oloye.
17 Mo si rán wọn ti awọn ti aṣẹ si ọdọ
do, olori ni ibi Kasifia, mo si kọ́ wọn li
ohun ti nwọn o wi fun Iddo, ati fun awọn
arakọnrin rẹ̀, awọn Netinimu ni ibi Kasifia,
ki nwọn ki o mu awọn iranṣẹ wá si ọdọ wa
fun ile Ọlọrun wa.
18 Ati nipa ọwọ rere Ọlọrun wa lara wa,
nwọn mu ọkọnrin oloye kan fun wa wá,
ninu awọn ọmọ Mali, ọmọ Lefi, ọmọ
Israeli; ati Ṣerebiah, pẹlu awọn ọmọ rẹ̀
ati awọn arakọnrin rẹ̀, mejidilogun.
19 Ati Haṣabiah, ati pẹlu rẹ̀ Jeṣaiah,
ninu awọn ọmọ Merari, awọn arakọnrin rẹ̀
pẹlu awọn ọmọ wọn, ogún;
20 Ninu awọn Netinimu pẹlu, ti Dafidi
ati awọn ijoye ti fi fun isin awọn ọmọ Lefi,
ogunlugba Netinimu gbogbo wọn li a kọ
orukọ wọn.
21 Nigbana ni mo kede àwẹ kan nibẹ
lẹba odò Ahafa, ki awa ki o le pọn ara wa
loju niwaju Ọlọrun wa, lati ṣafẹri ọ̀na titọ́
fun wa li ọwọ rẹ̀, ati fun ọmọ wẹrẹ wa, ati
fun gbogbo ini wa.
22 Nitoripe, oju ti mi lati bère ẹgbẹ
ọmọ-ogun li ọwọ ọba, ati ẹlẹṣin, lati ṣọ wa
nitori awọn ọta li ọ̀na: awa sa ti sọ fun
ọba pe, Ọwọ Ọlọrun wa mbẹ lara awọn ti
nṣe afẹri rẹ̀ fun rere; ṣugbọn agbara rẹ̀ ati
ibinu rẹ̀ mbẹ lara gbogbo awọn ti o kọ̀ ọ
silẹ.
23 Bẹ̃li awa gbàwẹ, ti awa si bẹ̀ Ọlọrun
wa nitori eyi: on si gbọ́ ẹ̀bẹ wa.
24 Nigbana ni mo yàn ẹni-mejila si ọ̀tọ
ninu awọn olori awọn alufa, Ṣerebiah,
Haṣabiah, ati mẹwa ninu awọn arakọnrin
wọn pẹlu wọn,
25 Mo si wọ̀n fàdaka ati wura fun wọn,
ati ohun-èlo, ani ọrẹ ti iṣe ti ile Ọlọrun,
wa, ti ọba ati awọn ìgbimọ rẹ̀ ati awọn
ijoye rẹ̀, ati gbogbo Israeli ti o wà nibẹ, ta
li ọrẹ:
26 Mo si wọ̀n ãdọtalelẹgbẹta talenti
fàdaka le wọn li ọwọ, ati ohun-èlo fàdaka,
ọgọrun talenti, ati ti wura, ọgọrun talenti,
27 Pẹlu ogun ago wura ẹlẹgbẹgbẹrun
dramu, ati ohun-èlo meji ti bàba daradara,
ti o niye lori bi wura.
28 Mo si wi fun wọn pe, Mimọ́ li ẹnyin
si Oluwa; mimọ́ si li ohun-èlo wọnyi; ọrẹ
atinuwa si Oluwa Ọlọrun awọn baba nyin
ni fàdaka ati wura na.
29 Ẹ ma tọju wọn, ki ẹ si ma pa wọn
mọ, titi ẹnyin o fi wọ̀n wọn niwaju awọn
olori ninu awọn alufa ati ọmọ Lefi, pẹlu
awọn olori ninu awọn baba Israeli ni Jeru-
salemu, ninu iyàrá ile Oluwa.
30 Bẹ̃ni awọn alufa ati awọn ọmọ Lefi
mu fàdaka ati wura ti a wọ̀n pẹlu ohunèlo

Digitized by Google

wọnni lati ko wọn wá si Jerusalemu, sinu ile Ọlọrun wa.

31 Nigbana ni awa lọ kuro ni odò Ahafa, li ọjọ ekejila oṣu ikini, lati lọ si Jerusalemu: ọwọ Ọlọrun wa si wà lara wa, o si gba wa lọwọ awọn ọta, ati lọwọ iru awọn ti o ba ni ibuba li ọ̀na.

32 Awa si de Jerusalemu, awa si simi nibẹ li ọjọ mẹta.

33 Li ọjọ ẹkẹrin li a wọ̀n fàdaka ati wura ati ohunèlo wọnni ninu ile Ọlọrun wa si ọwọ Meremoti ọmọ Uriah, alufa, ati pẹlu rẹ̀ ni Eleasari ọmọ Finehasi; ati pẹlu wọn ni Josabadi ọmọ Jeṣua, ati Noadia, ọmọ Binnui, awọn ọmọ Lefi;

34 Nipa iye, ati nipa ìwọn ni gbogbo wọn: a si kọ gbogbo ìwọn na sinu iwe ni igbana.

35 Ọmọ awọn ti a ti ko lọ, awọn ti o ti inu igbekùn pada bọ̀, ru ẹbọ sisun si Ọlọrun Israeli, ẹgbọrọ malu mejila, àgbo merindilọgọrun, ọdọ-agutan mẹtadilọgọrin, ati obukọ mejila fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ: gbogbo eyi jẹ ẹbọ sisun si Oluwa.

36 Nwọn si fi aṣẹ ọba fun awọn ijoye ọba, ati fun awọn balẹ ni ihahin odò: nwọn si ràn awọn enia na lọwọ, ati ile Ọlọrun.

## ORI 9.

NIGBATI a si ti ṣe nkan wọnyi tan, awọn ijoye wá si ọdọ mi, wipe, Awọn enia Israeli, ati awọn alufa, pẹlu awọn ọmọ Lefi kò ya ara wọn si ọ̀tọ kuro ninu awọn enia ilẹ wọnni, gẹgẹ bi irira wọn, ti awọn ara Kenaani, awọn ara Hitti, awọn ara Perisi, awọn ara Jebusi, awọn ara Ammoni, awọn ara Moabu, awọn ara Egipti, ati ti awọn ara Amori.

2 Nitoripe nwọn mu awọn ọmọ wọn obirin fun aya wọn, ati fun awọn ọmọ wọn ọkọnrin: tobẽ̩ ti a da iru-ọmọ mimọ́ pọ̀ mọ awọn enia ilẹ wọnni: ọwọ awọn ijoye, ati awọn olori si ni pataki ninu irekọja yi.

3 Nigbati mo si gbọ́ nkan wọnyi, mo fa aṣọ mi ati agbáda mi ya, mo si fà irun ori mi ati ti àgbọn mi tu kuro, mo si joko ni ijaya.

4 Nigbana ni olukuluku awọn ti o warìri si ọ̀rọ Ọlọrun Israeli ko ara wọn jọ si ọdọ mi, nitori irekọja awọn wọnni ti a ti ko lọ; mo si joko ni ijaya titi di igba ẹbọ aṣalẹ.

5 Ni igba ẹbọ aṣalẹ ni mo si dide kuro ninu ikãnu mi; pẹlu aṣọ ati agbáda mi yiya, mo si wolẹ lori ẽkun mi, mo si nà ọwọ mi si Oluwa Ọlọrun mi.

6 Mo si wipe, Ọlọrun mi, oju tì mi, isaju si ṣe mi lati gbe oju mi soke si ọdọ rẹ, Ọlọrun mi, nitoriti ẹ̀ṣẹ wa di pupọ li ori wa, ẹbi wa si tobi titi de awọn ọrun.

7 Lati ọjọ awọn baba wa li awa ti wà ninu ẹbi nla titi di oni; ati nitori ẹ̀ṣẹ wa li a fi awa, awọn ọba wa, ati awọn alufa wa, le awọn ọba ilẹ wọnni lọwọ fun idà, fun igbèkun, ati fun ikogun, ati fun idamu oju, gẹgẹ bi o ti ri li oni oloni.

8 Njẹ nisisiyi fun igba diẹ, li a si fi ore-ọfẹ fun wa lati ọdọ Oluwa Ọlọrun wa wá lati salà, ati lati fi ẽkàn fun wa ni ibi mimọ́ rẹ̀, ki Ọlọrun wa ki o le mu oju wa mọlẹ, ki o si tun wa gbe dide diẹ ninu okoẹrú wa.

9 Nitoripe ẹrú li awa iṣe; ṣugbọn Ọlọrun wa kò kọ̀ wa silẹ li oko ẹrú wa, ṣugbọn o ti nàwọ ãnu rẹ̀ si wa li oju awọn ọba Persia, lati tun mu wa yè, lati gbe ile Ọlọrun wa duro, ati lati tun ahoro rẹ̀ ṣe, ati lati fi odi kan fun wa ni Juda, ati ni Jerusalemu.

10 Njẹ nisisiyi, Ọlọrun wa, kili awa o wi lẹhin eyi? nitoriti awa ti kọ̀ aṣẹ rẹ silẹ,

11 Ti iwọ ti pa lati ẹnu awọn woli iranṣẹ rẹ wá, wipe, Ilẹ na ti ẹnyin nlọ igbà nì, ilẹ alaimọ́ ni, fun ẹgbin awọn enia ilẹ na, fun irira wọn, pẹlu ìwa-ẽri ti nwọn fi kun lati ikangun kan de ekeji.

12 Njẹ nitorina ki ẹnyin ki o máṣe fi ọmọ nyin obirin fun ọmọ wọn ọkọnrin, bẽni ki ẹnyin ki o máṣe mu ọmọ wọn obirin fun ọmọ nyin ọkọnrin, bẽni ki ẹnyin ki o máṣe wá alafia wọn tabi irọra wọn titi lai: ki ẹnyin ki o le ni agbara, ki ẹ si le ma jẹ ire ilẹ na, ki ẹ si le fi i silẹ fun awọn ọmọ nyin ni ini titi lai.

13 Ati lẹhin gbogbo eyi ti o de si wa nitori iṣe buburu wa, ati nitori ẹbi wa nla, nitoripe iwọ Ọlọrun wa ti dá wa si ju bi o ti yẹ lọ fun aiṣedede wa, o si fi iru igbala bi eyi fun wa;

14 Awa iba ha tun ru ofin rẹ? ki awa ki o si ma ba awọn enia irira wọnyi dá ana? iwọ ki o ha binu si wa titi iwọ o fi pa wa run tan, tobẽ̩ ti ẹnikan kò si ni kù, tabi ẹnikan ti o sala?

15 Olododo ni iwọ Oluwa Ọlọrun Israeli: awa ni iyokù ati asala gẹgẹ bi o ti ri li oni yi: wò o, awa duro niwaju rẹ ninu ẹbi wa, nitoripe awa ki o le duro niwaju rẹ nitori eyi.

Digitized by Google

## ORI 10.

ↄATI Esra ti gba adura, ti o si jẹwọ
.i ẹkun ati idojubolẹ niwaju ile Ọlọ-
ọ enia pupọ kó ara wọn jọ si ọdọ rẹ̀
u Israeli jade, ati ọkọnrin ati obirin
.ọ wẹwẹ: nitori awọn enia na sọkun
di.
ekaniah ọmọ Jehieli, lati inu awọn
Elamu dahùn o si wi fun Esra pe,
.i ṣẹ̀ si Ọlọrun wa, ti awa ti mu ajeji
lati inu awọn enia ilẹ na: sibẹ, ireti
un Israeli nipa nkan yi.
ſjẹ nitorina ẹ jẹ ki awa ki o ba Ọlọrun
majẹmu, lati kọ̀ gbogbo awọn obirin
ẹ, ati iru awọn ti nwọn bi gẹgẹ bi ìmọ
oluwa mi, ati ti awọn ti o warìri si
ọrun wa: ki awa ki o si mu u ṣẹ gẹgẹ
n na.
)ide! nitori ọ̀ran tirẹ li eyi: awa
yio wà pẹlu rẹ, mu ọkàn le ki o si

Esra si dide, o si mu awọn olori ninu
alufa, awọn ọmọ Lefi, ati gbogbo
li bura pe, awọn o ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ
i. Nwọn si bura.
Esra si dide kuro niwaju ile Ọlọrun, o
yara Johanani ọmọ Eliaṣibu lọ: ni-
o si lọ si ibẹ, on kò jẹ onjẹ, bẽni kò
ɔmi: nitoripe o nṣọ̀fọ nitori irekọja
ti a kó lọ.
Nwọn si kede ja gbogbo Juda ati
salemu fun gbogbo awọn ọmọ igbè-
ki nwọn ki o kó ara wọn jọ pọ̀ si
salemu;
Ati pe ẹnikẹni ti kò ba wá niwọ̀n ijọ
, gẹgẹ bi ìmọ awọn olori ati awọn
, gbogbo ini rẹ̀ li a o jẹ, on tikararẹ̀
ɔ si yà kuro ninu ijọ awọn enia ti a ti
ọ.
Nitori eyi ni gbogbo awọn enia Juda
Benjamini ko ara wọn jọ pọ̀ ni ọjọ
a si Jerusalemu, li oṣu kẹsan, li ogun
ɔṣu; gbogbo awọn enia si joko ni ita
Ọlọrun ni iwarìri nitori ọ̀ran yi, ati
ri òjo-pupọ.
0 Nigbana ni Esra alufa dide duro, o si
fun wọn pe, Ẹnyin ti ṣẹ̀, ẹnyin ti mu
i obirin ba nyin gbe lati sọ ẹ̀ṣẹ Israeli
pupọ,
1 Njẹ nitorina, ẹ jẹwọ fun Oluwa Ọlọrun
n baba nyin, ki ẹnyin ki o si mu ifẹ rẹ̀
ki ẹnyin ki o si ya ara nyin kuro ninu
ɔn enia ilẹ na, ati kuro lọdọ awọn ajeji
rin.
2 Nigbana ni gbogbo ijọ enia na dahùn,
nwọn si wi li ohùn rara pe, Bi iwọ ti wi,
bẽni awa o ṣe.
13 Ṣugbọn awọn enia pọ̀, igba òjo pupọ
si ni, awa kò si le duro nita, bẽni eyi ki
iṣe iṣẹ ọjọ kan tabi meji: nitoriti awa ti
ṣẹ̀ pupọpupọ ninu ọ̀ran yi.
14 Njẹ jẹ ki awọn olori wa ki o duro
fun gbogbo ijọ enia, ki a si jẹ ki olukuluku
ninu ilu wa ti o mu ajeji obirin ba wọn
gbe, ki o wá ni wakati ti a da, ati awọn
olori olukuluku ilu pẹlu wọn, ati awọn
onidajọ wọn, titi a o fi yi ibinu kikan
Ọlọrun wa pada kuro lọdọ wa nitori ọ̀ran
yi.
15 Sibẹ Jonatani ọmọ Asaheli, ati Jaha-
siah ọmọ Tikfa li o dide si eyi, Meṣul-
lamu ati Ṣabbetai, ọmọ Lefi, si ràn wọn
lọwọ.
16 Ṣugbọn awọn ọmọ igbekun ṣe bẽ.
Ati Esra, alufa, pẹlu awọn olori ninu awọn
baba, nipa ile baba wọn, ati gbogbo wọn
nipa orukọ wọn li a yà si ọ̀tọ, ti nwọn
si joko li ọjọ kini oṣu kẹwa, lati wadi
ọ̀ran na.
17 Nwọn si ba gbogbo awọn ọkọnrin ti
o mu ajeji obirin ba wọn gbe ṣe aṣepari, li
ọjọ ekini oṣu ekini,
18 Ati ninu awọn ọmọ awọn alufa, a ri
awọn ti o mu ajeji obirin ba wọn gbe: ninu
awọn ọmọ Jeṣua, ọmọ Josadaki, ati awọn
arakọnrin rẹ̀; Maaseiah, ati Elieseri, ati
Jaribi ati Gedaliah.
19 Nwọn si fi ọwọ wọn fun mi pe: awọn
o kọ̀ awọn obirin wọn silẹ; nwọn si fi àgbo
kan rubọ ẹ̀ṣẹ nitori ẹbi wọn.
20 Ati ninu awọn ọmọ Immeri; Hanani
ati Sebadiah.
21 Ati ninu awọn ọmọ Harimu; Maase-
iah, ati Elijah, ati Ṣemaiah, ati Jehieli, ati
Ussiah.
22 Ati ninu awọn ọmọ Paṣuri; Elioenai,
Maaseiah, Iṣmaeli, Nataneeli Josabadi, ati
Eleasa.
23 Ati ninu awọn ọmọ Lefi; Josabadi,
ati Ṣimei, ati Kelaiah (eyi ni Kelita)
Petahiah, Juda, ati Elieseri.
24 Ninu awọn akọrin pẹlu; Eliaṣibu:
ati ninu awọn adèna; Ṣallumu, ati Telemi,
ati Uri.
25 Pẹlupẹlu ninu Israeli: ninu awọn
ọmọ Paroṣi: Ramiah, ati Jesiah, ati Mal-
kiah, ati Miamini, ati Eleasari, ati Malki-
jah, ati Benaiah.
26 Ati ninu awọn ọmọ Elamu; Mat-
taniah, Sekariah, ati Jehieli, ati Abdi, ati
Jeremoti, ati Eliah.

Digitized by Google

27 Ati ninu awọn ọmọ Sattu ; Elioenai,
Eliaṣibu, Mattaniah, ati Jeremoti, ati Sa-
badi, ati Asisa.
28 Ninu awọn ọmọ Bebai pẹlu ; Jeho-
hanani, Hananiah, Sabbai ati Atlai.
29 Ati ninu awọn ọmọ Bani ; Meṣul-
lamu, Malluki, ati Adaiah, Jaṣubu, ati
Ṣeali ati Ramoti.
30 Ati ninu awọn ọmọ Pahat-moabu
Adma ati Kelali, Benaiah, Maaseiah, Mat-
taniah, Besaleeli, ati Binnui, ati Manasse.
31 Ati ninu awọn ọmọ Harimu : Elie-
seri, Iṣṣijah, Malkiah, Ṣemaiah, Ṣimeoni,
32 Benjamini, Malluki, ati Ṣemariah.
33 Ninu awọn ọmọ Haṣumu ; Mattenai,
Mattatta, Sabadi, Elifeleti, Jeremai, Man-
asse, ati Ṣimei,
34 Ninu awọn ọmọ Bani ; Maadai, Am-
ramu ati Ueli.
35 Benaiah, Bedeiah, Kellu,
36 Faniah, Meremoti, Eliaṣibu,
37 Mattaniah, Mattenai ati Jaasau,
38 Ati Bani, ati Binnui, Ṣimei.
39 Ati Ṣelemiah, ati Natani, ati Adaiah,
40 Maknadebai, Saṣai, Ṣarai,
41 Asareeli, ati Ṣelemiah, Ṣemariah.
42 Ṣallumu, Amariah, ati Josefu.
43 Ninu awọn ọmọ Nebo ; Jeieli, Mat-
titiah, Sabadi, Ṣebina, Jadau, ati Joeli,
Benaiah.
44 Gbogbo awọn yi li o mu ajeji obirin
ba wọn gbe, omiran ninu wọn si ni obirin
nipa ẹniti nwọn li ọmọ.

---

IWE

# NEHEMIAH.

## ORI 1.

ỌRỌ Nehemiah ọmọ Hakaliah. O si ṣe
ninu oṣu Kisleu, li ogún ọdun, ni-
gbati mo wà ni Ṣuṣani ãfin.
2 Ni Hanani, ọkan ninu awọn arakọnrin
mi, on ati awọn ọkọnrin kan lati Juda wá
sọdọ mi ; mo si bi wọn lere niti awọn ara
Juda ti o salà, ti o kù ninu awọn igbekùn,
ati niti Jerusalemu.
3 Nwọn si wi fun mi pe, Awọn iyokù,
ti a fi silẹ nibẹ ninu awọn igbekùn ni
igberiko, mbẹ ninu wahala nla ati ẹgan :
odi Jerusalemu si wó lulẹ̀, a si fi ilẹkùn
rẹ̀ jọná.
4 O si ṣe nigbati mo gbọ́ ọ̀rọ wọnyi,
mo joko, mo si sọkun, mo si ṣọ̀fọ ni iye
ọjọ, mo si gbãwẹ, mo si gbàdua niwaju
Ọlọrun ọrun.
5 Mo si wipe, Emi mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ,
Oluwa Ọlọrun ọrun, ti o tobi, ti o si li
ẹ̀ru, ti npa majẹmu ati ãnu mọ fun awọn
ti o fẹ ẹ, ti nwọn si pa ofin rẹ̀ mọ :
6 Tẹ́ eti rẹ silẹ̀ nisisiyi, ki o si ṣi oju
rẹ, ki iwọ ba le gbọ́ adura iranṣẹ rẹ, ti
mo ngbà niwaju rẹ nisisiyi, tọsan toru
fun awọn ọmọ Israeli iranṣẹ rẹ, ti mo si
jẹwọ ẹ̀ṣẹ awọn ọmọ Israeli ti a ti ṣẹ̀ si ọ :
ati emi ati ile baba mi ti ṣẹ̀.
7 Awa ti huwa ibàjẹ si ọ, awa kò si
pa ofin ati ilana ati idajọ mọ, ti iwọ pa
li aṣẹ fun Mose iranṣẹ rẹ.
8 Emi bẹ̀ ọ, ranti ọ̀rọ ti iwọ pa laṣẹ fun
Mose iranṣẹ rẹ, wipe, Bi ẹnyin ba ṣẹ̀ emi
o tú nyin kakiri sãrin awọn orilẹ-ède :
9 Ṣugbọn bi ẹnyin ba yipada si mi,
ti ẹ si pa ofin mi mọ, ti ẹ si ṣe wọn, bi
o tilẹ ṣepe ẹnyin ti a ti tì jade wà ni
ipẹkun ọrun, emi o ko wọn jọ lati ibẹ
wá, emi o si mu wọn wá si ibi ti mo ti
yàn lati fi orukọ mi si.
10 Njẹ awọn wọnyi ni awọn iranṣẹ rẹ
ati enia rẹ, ti iwọ ti rà pada nipa agbara
rẹ nla ati nipa ọwọ agbara rẹ.
11 Oluwa, emi bẹ ọ, tẹ́ eti rẹ silẹ si
adura iranṣẹ rẹ, ati si adura awọn iranṣẹ
rẹ, ti o fẹ lati bẹ̀ru orukọ rẹ: emi bẹ ọ,
ki o si ṣe rere si iranṣẹ rẹ loni, ki o si fun
u li ãnu li oju ọkọnrin yi. Nitori agbe-
ago ọba li emi jẹ.

## ORI 2.

O SI ṣe li oṣu Nisani, li ogún ọdun Arta-
sasta ọba, ọti-waini wà niwaju rẹ̀ :

Digitized by Google

mo si gbe ọti-waini na, mo si fi fun ọba.
Emi kò si ti ifajuro niwaju rẹ̀ rí.
2 Nitorina ni ọba ṣe wi fun mi pe, ẽṣe
ti oju rẹ fi faro? iwọ kò sa ṣaisan? eyi
kì iṣe ohun miran bikoṣe ibanujẹ. Ẹru
si ba mi gidigidi.
3 Mo si wi fun ọba pe, Ki ọba ki o pẹ:
ẽṣe ti oju mi kì yio fi faro, nigbati ilu, ile
iboji awọn baba mi dahoro, ti a si fi iná
sun ilẹkun rẹ̀?
4 Nigbana ni ọba wi fun mi pe, ẹ̀bẹ
kini iwọ fẹ bẹ̀? Bẹ̃ni mo gbadura si Ọlọrun
ọrun.
5 Mo si wi fun ọba pe, Bi o ba wù ọba,
ati bi iranṣẹ rẹ ba ri ojurere lọdọ rẹ, ki
iwọ le rán mi lọ si Juda, si ilu iboji awọn
baba mi, ki emi ki o ba le kọ́ ọ.
6 Ọba si wi fun mi pe, (ayaba si joko tì
i) ajo rẹ yio ti pẹ to? nigbawo ni iwọ o
si pada? Bẹli o wù ọba lati rán mi; mo
si dá àkoko kan fun u.
7 Pẹlupẹlu mo wi fun ọba pe, Bi o ba
wù ọba, ki o fun mi ni iwe si awọn bãlẹ
li oke odò, ki nwọn le mu mi kọja titi emi
o fi de Juda;
8 Ati iwe kan fun Asafu, oluṣọ igbo ọba,
ki o le fun mi ni igi fun atẹrigba ẹnu-ọ̀na
odi lẹba ile Ọlọrun ati fun odi ilu, ati fun
ile ti emi o wọ̀. Ọba si fun mi gẹgẹ bi
ọwọ rere Ọlọrun mi lara mi.
9 Nigbana ni mo de ọdọ awọn bãlẹ li
oke odo, mo si fi iwe ọba fun wọn: Ọba
si ti rán awọn olori-ogun ati ẹlẹṣin pẹlu mi.
10 Nigbati Sanballati ara Horoni ati
Tobiah iranṣẹ ara Ammoni gbọ́, o bi wọn
ni inu gidigidi pe, enia kan wá lati wá ire
awọn ọmọ Israeli.
11 Bẹ̃ni mo de Jerusalemu, mo si wà
nibẹ̀ ni ọjọ mẹta.
12 Mo si dide li oru, emi ati ọkọnrin
diẹ pẹlu mi: emi kò si sọ fun enia kan
ohun ti Ọlọrun mi fi si mi li ọkàn lati ṣe
ni Jerusalemu: bẹni kò si ẹranko kan pẹlu
mi, bikoṣe ẹranko ti mo gùn.
13 Mo si jade li oru ni ibode afonifoji,
ani niwaju kanga Dragoni, ati li ẹnu-ọ̀na
ãtàn; mo si wò odi Jerusalemu ti a wó
lulẹ̀, ati ẹnu-ọ̀na ti a fi iná sun.
14 Nigbana ni mo lọ si ẹnu-ọ̀na orisun,
ati si àbata ọba: ṣugbọn kò si àye fun
ẹranko ti mo gun lati kọja.
15 Nigbana ni mo goke lọ li oru lẹba
odò, mo si wò odi na: mo si yipada, mo
si tún wọ̀ bode afonifoji, mo si yipada.
16 Awọn ijoye kò si mọ̀ ibi ti mo lọ,
tabi ohun ti mo ṣe; emi kò ti isọ fun
awọn ara Juda tabi fun awọn alufa, tabi
fun awọn alagba, tabi fun awọn ijoye;
tabi fun awọn iyokù ti o ṣe iṣẹ na.
17 Nigbana ni mo wi fun wọn pe, Ẹnyin
ri ibanujẹ ti awa wà, bi Jerusalemu ti di
ahoro, ẹnu-ọ̀na rẹ̀ li a si fi iná sun: ẹ wá,
ẹ jẹ ki a mọ odi Jerusalemu, ki a má ba
jẹ ẹni-ẹgàn mọ!
18 Nigbana ni mo si sọ fun wọn niti
ọwọ Ọlọrun mi, ti o dara li ara mi; ati
ọ̀rọ ọba ti o ba mi sọ. Nwọn si wipe, Jẹ
ki a dide, ki a si mọ odi! Bẹ̃ni nwọn gba
ara wọn ni iyanju fun iṣẹ rere yi.
19 Ṣugbọn nigbati Sanballati ara Ho-
roni, ati Tobiah iranṣẹ, ara Ammoni, ati
Gesẹmu, ara Arabia, gbọ́, nwọn fi wa rẹrin
ẹlẹya, nwọn si gàn wa, nwọn si wipe, Kini
ẹnyin nṣe yi? ẹnyin o ha ṣọtẹ si ọba bi?
20 Nigbana ni mo da wọn li ohùn mo
si wi fun wọn pe, Ọlọrun ọrun, On o ṣe
rere fun wa; nitorina awa iranṣẹ rẹ̀ yio
dide lati mọ odi: ṣugbọn ẹnyin kò ni ipin
tabi ipa tabi ohun iranti ni Jerusalemu.

## ORI 3.

NIGBANA ni Eliaṣibu olori alufa dide
pẹlu awọn alufa arakọnrin rẹ̀, nwọn
si mọ ẹnu-bode agutan; nwọn sọ ọ di
mimọ́, nwọn si gbe ilẹkùn rẹ̀ duro, titi de
ile-iṣọ Mea, ni nwọn sọ di mimọ́ titi de
ile-iṣọ Hananeeli.
2 Lọwọkọwọ rẹ̀ ni awọn ọkọnrin Jeriko
si mọ: lọwọkọwọ wọn ni Sakkuri ọmọ
Imri si mọ.
3 Ṣugbọn ẹnu-bode Ẹja ni awọn ọmọ
Hasenaa mọ, ẹniti o tẹ̀ igi idabu rẹ̀, ti
o si gbe ilẹkun rẹ̀ ro, àgadágodo rẹ̀, ati
itikùn rẹ̀.
4 Lọwọkọwọ wọn ni Meremoti ọmọ
Urijah, ọmọ Kosi, tun ṣe. Ati lọwọkọwọ
wọn ni Maṣullamu, ọmọ Berekiah, ọmọ
Meṣesabeli tun ṣe. Ati lọwọkọwo wọn ni
Sadoku, ọmọ Baana tun ṣe.
5 Ati lọwọkọwọ wọn ni awọn ará Tekoa
tun ṣe, ṣugbọn awọn ọlọla kò fi ọrùn si
iṣẹ Oluwa wọn.
6 Jehoida, ọmọ Pasea, ati Meṣullamu,
ọmọ Besodiah, si tun ẹnu-bode atijọ ṣe,
nwọn tẹ̀ igi idabu rẹ̀, nwọn si gbe ilẹkùn
rẹ̀ ro, ati àgadágodo rẹ̀, ati itikùn rẹ̀.
7 Lọwọkọwọ wọn ni Melatiah, ará Gi-
beoni, tun ṣe, ati Jadoni, ara Merono,
awọn ọkọnrin ti Gibeoni, ati ti Mispa, ti
o jẹ ti itẹ bãlẹ̀ apa ihin odò.
8 Lọwọkọwọ rẹ̀ ni Ussieli ọmọ Harhiah,
alagbẹdẹ wura tun ṣe; ati lọwọkọwọ rẹ̀ ni

Digitized by Google

Hananjah ọmọ alapolu, tun ṣe; nwọn si
ti fi Jerusalemu silẹ titi de odi gbigbõro.
9 Lọwọkọwọ wọn ni Refaiah, ọmọ Huri,
ijòye idaji Jerusalemu si tun ṣe.
10 Lọwọkọwọ wọn ni Jedaiah, ọmọ
Harumafu, si tun ṣe, ani ọkánkan ile rẹ.
Lọwọkọwọ rẹ ni Hattuṣi ọmọ Haṣabaniah
si tun ṣe.
11 Malkijah ọmọ Harimu, ati Haṣubu
ọmọ Pahati-Moabu, tun apa keji ṣe, ati
ile-iṣọ ileru.
12 Ati lọwọkọwọ rẹ Ṣallumu ọmọ Halo-
heṣi, ijòye apa kan Jerusalemu, tun ṣe, on
ati awọn ọmọbirin rẹ.
13 Hanuni pẹlu awọn ará Sanoa si tun
ẹnubode afonifoji ṣe; nwọn kọ́ ọ, nwọn si
gbe ilẹkùn rẹ ro, àgadágodo rẹ ati itikùn
rẹ, ati ẹgbẹrun igbọnwọ odi titi de ẹnu-
bode ãtàn.
14 Ẹnu-bode ãtàn ni Malkiah ọmọ Re-
kabu, ijòye apakan Bet-hakkeremu tun
ṣe; o kọ́ ọ, o gbe ilẹkùn rẹ ro, àgadágodo
rẹ ati itikun rẹ.
15 Ṣallumu, ọmọ Kol-hose, ijòye apakan
Mispa si tun ẹnu-bode orisun ṣe; o kọ́ ọ, o
si bò o, o si gbe ilẹkùn rẹ ro, àgadágodo rẹ,
ati itikun rẹ ati odi adagun Ṣiloa li ẹ̀ba
ọgba ọba, ati titi de atẹgun ti o sọkalẹ lati
ilu Dafidi lọ.
16 Lẹhin rẹ ni Nehemiah, ọmọ Asbuku,
ijòye idaji Bet-huri, tun ṣe titi de ibi
ọkánkán iboji Dafidi, ati de adagun ti a ṣe,
ati titi de ile awọn alagbara.
17 Lẹhin rẹ ni awọn ọmọ Lefi, Rehemu,
ọmọ Bani tun ṣe. Lẹhin rẹ ni Haṣabiah
ijòye idaji Keila tun ṣe li apa tirẹ.
18 Lẹhin rẹ ni awọn arakọnrin wọn tun
ṣe, Bafai ọmọ Henadadi, ijoye idaji Keilah.
19 Lọwọkọwọ rẹ ni Eseri ọmọ Jeṣua,
ijòye Mispa, tun apa miran ṣe li ọkánkán
titọ lọ si ile-ihamọra kọrọ̀ odi.
20 Lẹhin rẹ ni Baruku ọmọ Sabbai fi
itara tun apa miran ṣe, lati igun ogiri titi
de ilẹkùn ile Eliaṣibu, olori alufa.
21 Lẹhin rẹ ni Meremoti ọmọ Urijah,
ọmọ Kosi tun apa miran ṣe lati ilẹkùn ile
Eliaṣibu titi de ipẹkun ile Eliaṣibu.
22 Lẹhin rẹ ni awọn alufa si tun ṣe,
awọn ọkọnrin pẹtẹlẹ [Jordani].
23 Lẹhin wọn ni Benjamini ati Haṣubu
tun ṣe li ọkánkán ile wọn. Lẹhin wọn ni
Asariah ọmọ Maasiah ọmọ Ananiah tun ṣe
lẹba ile rẹ.
24 Lẹhin rẹ ni Binnui, ọmọ Henadadi
tun apa miran ṣe, lati ile Asariah titi de
igun odi, ani titi de kọrọ̀.
25 Palali ọmọ Usai li ọkánkán igun odi,
ati ile-iṣọ ti o yọ sode lati ile giga ti ọba
wá ti o wà lẹba iletubu. Lẹhin rẹ ni
Padaiah ọmọ Paroṣi.
26 Ṣugbọn awọn Netinimu gbe Ofẹli,
titi de ọkánkán ẹnu-bode omi niha ila-õrùn
ati ile-iṣọ ti o yọ sode.
27 Lẹhin wọn ni awọn ara Tekoa tun
apa miran ṣe, li ọkánkán ile-iṣọ nla ti o
yọ sode, titi de odi Ofeli.
28 Lati oke ẹnu-bode ẹṣin ni awọn alufa
tun apa miran ṣe, olukuluku li ọkánkán
ile rẹ.
29 Lẹhin wọn ni Sadoku, ọmọ Immeri
tun ṣe li ọkánkán ile rẹ; lẹhin rẹ ni
Ṣemaiah ọmọ Ṣekaniah, olùtọju ẹnubode
ila-õrùn tun ṣe.
30 Lẹhin wọn ni Hananiah ọmọ Sela-
miah tun ṣe, ati Hanuni ọmọ Salafa kẹfa
tun apa miran ṣe. Lẹhin rẹ ni Meṣullamu,
ọmọ Berekiah li ọkánkán yàra rẹ.
31 Lẹhin rẹ ni Malkiah ọmọ alagbẹdẹ
wura tun ṣe, titi de ile awọn Netinimu ati
ti awọn oniṣòwo, li ọkánkán ẹnu-bode
Mifkadi ati yàra òke igun-odi.
32 Ati larin yàra òke igun-odi titi de
ẹnu-bode agutan ni awọn alagbẹdẹ wura ati
awọn oniṣòwo tun ṣe.

## ORI 4.

O SI ṣe, nigbati Sanballati gbọ́ pe awa mọ
odi na, inu rẹ rú, o si binu pupọ o si
gàn awọn ara Juda.
2 O si sọ niwaju awọn arakọnrin rẹ ati
awọn ọmọ-ogun Samaria pe, Kini awọn
alailera Juda wọnyi nṣe yi? nwọn o ha dá
wà fun ara wọn bi? nwọn o ha rubọ?
nwọn o ha ṣe aṣepari ni ijọkan? nwọn o ha
mu okuta ti a ti sun lati inu okiti sọji?
3 Tobiah ara Ammoni si wà li eti ọ̀dọ
rẹ, o si wipe, Eyi ti nwọn mọ gidi, bi
kọ̀lọkọlọ ba gùn u, yio tilẹ wo odi okuta
wọn lulẹ.
4 Gbọ́, Ọlọrun wa; nitoriti awa di ẹni
ẹ̀gan: ki iwọ ki o si dà ẹgan wọn si ori ara
wọn, ki o si fi wọn fun ikogun ni ilẹ ìgbe-
kun.
5 Ki o má si bo irekọja wọn, má si jẹ ki
a wẹ ẹ̀ṣẹ wọn nù kuro niwaju rẹ: nitoriti
nwọn bi ọ ni inu niwaju awọn ọ̀mọle,
6 Bẹ́ni awa mọ odi na: gbogbo odi na ni
a si mọ kàn ara wọn titi de idameji rẹ:
nitori awọn enia na ni ọkàn lati ṣiṣẹ.
7 O si ṣe, nigbati Sanballati, ati Tobiah,
ati awọn ara Arabia, ati awọn ara Ammoni,

Digitized by Google

wọn ara Aṣdodi gbọ́ pe, a mọ odi Jeru-
nu de oke, ati pe a bẹ̀rẹ si tun ibi ti o
ɜ, inu wọn ru gidigidi.
Gbogbo wọn si jọ gbìmọ pọ̀ lati wá iba
salemu jà, ati lati ṣe ikà si i.
Ṣugbọn awa gba adura wa si Ọlọrun
a si yan iṣọ si wọn lọsan ati loru, nitori
ı.
) Juda si wipe, Agbara awọn ti nru
bùku, àlapa pupọ li o wà, tobẹ̃ ti awa
ì le mọ odi na.
1 Awọn ọta wa si wipe, Nwọn kì yio
bẹ̃ni nwọn kì yio ri titi awa o fi de
ı wọn, ti a o fi pa wọn, ti a o si da iṣẹ
luro.
2 O si ṣe, nigbati awọn ara Juda ti o
li agbegbe wọn de, nwọn wi fun wa
ba mẹwa pe, Lati ibi gbogbo wá li ẹnyin
ada tọ̀ wa wá.
.3 Nitorina ni mo yàn awọn enia si ibi
ɔ rẹlẹ lẹhin odi, ati si ibi gbangba, mo
ı yàn awọn ẹnia gẹgẹ bi idile wọn, pẹlu
wọn, ọ̀kọ wọn, ati ọrun wọn.
14 Mo si wò, mo si dide, mo si wi fun
ọn ìjoye, ati fun awọn olori, ati fun
ọn enia iyokù pe, Ẹ máṣe jẹ ki ẹ̀ru wọn
nyin, ẹ ranti Oluwa ti o tobi, ti o si li
ı, ki ẹ si jà fun awọn arakọnrin nyin,
ọn ọmọkọnrin nyin, ati awọn ọmọbirin
in, awọn aya nyin, ati ile nyin.
15 O si ṣe, nigbati awọn ọta wa gbọ́ pe,
li mimọ̀ fun wa, Ọlọrun ti sọ ìmọ wọn di
ın, gbogbo wa si padà si odi na, oluku-
ku si iṣẹ rẹ̀.
16 O si ṣe, lati ọjọ na wá, idaji awọn
ıọkọnrin mi ṣe iṣẹ na, idaji keji di ọ̀kọ,
ata, ati ọrun, ati ihamọra mu; awọn
ori si duro lẹhin gbogbo ile Juda.
17 Awọn ti nmọ odi, ati awọn ti nrù
ù ati awọn ti o si ndi ẹrù, olukuluku wọn
ì ọwọ rẹ̀ kan ṣe iṣẹ, nwọn si fi ọwọ keji
. ohun ìja mu.
18 Olukuluku awọn ọmọ kọ́ idà rẹ̀ li
;bẹ rẹ̀, bẹni nwọn si mọ odi. Ẹniti nfọn
ıè wà li eti ọdọ mi.
19 Mo si sọ fun awọn ijoye, ati fun awọn
lori, ati fun awọn enia iyokù pe, Iṣẹ na
ıbi o si pọ̀, a si ya ara wa lori odi ẹnikini
na si ẹnikeji.
20 Ni ibi ti ẹnyin ba gbọ́ iro ipe, ki ẹ wá
ọdọ wa: Ọlọrun wa yio jà fun wa.
21 Bẹ̃ni awa ṣe iṣẹ na: idaji wọn di ọ̀kọ
ıu lati kùtukutu owurọ titi irawọ fi yọ.
22 Li àkoko kanna pẹlu ni mo sọ fun
wọn enia pe, Jẹ ki olukuluku pẹlu ọmọ-
ọnrin rẹ̀ ki o sùn ni Jerusalemu, ki nwọn
le jẹ ẹṣọ fun wa li oru, ki nwọn si le ṣe iṣẹ
li ọsan.
23 Bẹ̃ni kì iṣe emi, tabi awọn arakọnrin
mi, tabi awọn ọmọkọnrin mi, tabi awọn
oluṣọ ti ntọ̀ mi lẹhin, kò si ẹnikan ninu
wa ti o bọ́ aṣọ kuro, olukuluku mu ohun
ìja rẹ̀ li ọwọ fun omi.

## ORI 5.

AWỌN enia ati awọn aya wọn si nkigbe
nlanla si awọn ara Juda, arakọnrin
wọn.
2 Nitori awọn kan wà ti nwọn wipe,
Awa, awọn ọmọkọnrin wa, ati awọn ọmọ-
birin wa, jẹ pipọ: nitorina awa gba ọkà,
awa si jẹ, a si yè.
3 Awọn ẹlomiran wà pẹlu ti nwọn wipe,
Awa ti fi oko wa, ọgba-ajara wa, ati ile wa,
sọfa, ki awa ki o le rà ọkà ni ìgba ìyan.
4 Ẹlomiran si wipe, Awa ti ṣi owo lati
san owo-ori ọba li ori oko wa, ati ọgba-
ajara wa.
5 Ati sibẹ ẹran-ara wa si dabi ẹran-ara
awọn arakọnrin wa, ọmọ wa bi ọmọ wọn:
si wo o, awa mu awọn ãrakọnrin wa ati
awọn arabirin wa wá si oko-ẹrú, lati jẹ
iranṣẹ, a si ti mu ninu awọn ọmọbirin wa
wá si oko-ẹrú na: awa kò ni agbara lati rà
wọn padà: nitori awọn ẹlomiran li o ni
oko wa ati ọgbà-ajara wa.
6 Emi si binu gidigidi nigbati mo gbọ́
igbe wọn ati ọ̀rọ wọnyi.
7 Mo si ronu ọ̀ran na, mo si ba awọn
ijoye ati awọn olori wi, mo si wi fun wọn
pe, Ẹnyin ngba ẹdá olukuluku lọwọ ara-
kọnrin rẹ̀. Mo si pe apejọ nla tì wọn.
8 Mo si wi fun wọn pe, Awa nipa agbara
wa ti rà awọn ara Juda arakọnrin wa padà,
ti a tà fun awọn keferi; ẹnyin o ha si mu
ki a tà awọn arakọnrin nyin? tabi ki a ha
tà wọn fun wa? Nwọn si dakẹ, nwọn kò
ri nkankan dahùn.
9 Mo si wi pẹlu pe, Ohun ti ẹ ṣe kò
dara: kò ha yẹ ki ẹ ma rìn ninu ìbẹru
Ọlọrun wa, nitori ẹgan awọn keferi ọta wa?
10 Emi pẹlu, ati awọn arakọnrin mi, ati
awọn ọmọkọnrin mi, ti ṣí wọn li owo ati li
ẹdá ọkà: mo bẹ̀ nyin, ẹ jẹ ki a fi ẹdá gbi-
gbà yi silẹ̀.
11 Mo bẹ̀ nyin, ẹ fi oko wọn, ọgbà-ajara
wọn, ọgbà-olifi wọn, ati ile wọn, ida-ọgọrun
owo na pẹlu, ati ti ọkà, ọti-waini, ati ororo
wọn, ti ẹ fi agbara gbà, fun wọn padà loni
yi.
12 Nwọn si wipe, Awa o fi fun wọn pa-
da, awa kì yio si bere nkankan lọwọ wọn;

Digitized by Google

bẹ̃li awa o ṣe bi iwọ ti wi. Nigbana ni mo
pe awọn alufa, mo si mu wọn bura pe,
nwọn o ṣe gẹgẹ bi ileri yi.
13 Mo si gbọ̀n apo aṣọ mi, mo si wipe,
Bayi ni ki Ọlọrun ki o gbọ̀n olukuluku
enia kuro ni ile rẹ̀, ati kuro ninu iṣẹ rẹ̀, ti
kò mu ileri yi ṣẹ, ani bayi ni ki a gbọ̀n ọ
kuro, ki o si di ofo. Gbogbo ijọ si wipe,
Amin! nwọn si fi iyìn fun Oluwa. Awọn
enia na si ṣe gẹgẹ bi ileri yi.
14 Pẹlupẹlu lati akoko ti a ti yàn mi
lati jẹ bãlẹ wọn ni ilẹ Juda, lati ogún ọdun
titi de ọdun kejilelọgbọn Artasasta ọba,
eyinì ni, ọdun mejila emi ati awọn arakọn-
rin mi kò jẹ onjẹ bãlẹ.
15 Ṣugbọn awọn bãlẹ iṣaju, ti o ti wà
ṣaju mi, di ẹrù wiwo le lori awọn enia,
nwọn si ti gbà akara ati ọti-waini, laika
ogoji ṣekeli fadaka; pẹlupẹlu awọn ọmọ-
kọnrin wọn tilẹ lo agbara lori enia na:
ṣugbọn emi kò ṣe bẹ̃ nitori ibẹ̀ru Ọlọrun.
16 Mo si mba iṣẹ odi yi lọ pẹlu, awa kò
si rà oko kan: gbogbo awọn ọmọkọnrin
mi li o si gbajọ sibẹ si iṣẹ na.
17 Pẹlupẹlu awọn ti o joko ni tabili mi
jẹ ãdọjọ enia ninu awọn ara Juda ati ninu
awọn ijoye, laika awọn ti o wá sọdọ wa lati
ãrin awọn keferi ti o wà yi wa ka.
18 Njẹ ẹran ti a pese fun mi jẹ malũ
kan ati ãyo agutan mẹfa; fun ijọ kan ni a
pese adiẹ fun mi pẹlu, ati lẹ̃kan ni ijọ mẹ-
wa onirũru ọti-waini: ṣugbọn fun gbogbo
eyi emi kò bere onjẹ bãlẹ, nitori iṣẹ na wi-
wo lori awọn enia yi.
19 Ranti mi, Ọlọrun mi, fun rere, gẹgẹ
bi gbogbo eyi ti mo ti ṣe fun enia yi.

## ORI 6.

O SI ṣe, nigbati Sanballati, ati Tobiah,
ati Geṣemu, ara Arabia, ati awọn ọta
wa iyokù, gbọ́ pe, mo ti mọ odi na, ati pe,
kò kù ibi yiya kan ninu rẹ̀, (bi emi kò tilẹ
iti gbe ilẹkùn wọnni ro ni ibode li akoko
na;)
2 Ni Sanballati ati Geṣemu ranṣẹ si mi,
wipe, Wá, jẹ ki a jọ pade ninu ọkan ninu
awọn ileto ni pẹtẹlẹ Ono. Ṣugbọn nwọn
ngbero ati ṣe mi ni ibi.
3 Mo si ran onṣẹ si wọn pe, Emi nṣe iṣẹ
nla kan, emi kò le sọkalẹ wá: ẽṣe ti iṣẹ na
yio fi duro nigbati mo ba fi i silẹ, ti mo ba
si sọkalẹ tọ̀ nyin wá?
4 Sibẹ nwọn ranṣẹ si mi nigba mẹrin
bayi; mo si da wọn lohùn bakanna.
5 Nigbana ni Sanballati rán ọmọ-ọdọ rẹ̀
si mi bakanna nigba karun ti on ti iwe ṣíṣi
lọwọ rẹ̀.
6 Ninu rẹ̀ li a kọ pe, A nrohin lãrin
awọn keferi, Gaṣimu si wi pe, iwọ ati awọn
ara Juda rò lati ṣọ̀tẹ: nitori idi eyi ni iwọ
ṣe mọ odi na, ki iwọ le jẹ ọba wọn, gẹge bi
ọ̀rọ wọnyi.
7 Iwọ pẹlu si ti yan awọn woli lati kede
rẹ ni Jerusalemu wipe, Ọba wà ni Juda:
nisisiyi ni a o si rò o fun ọba gẹgẹ bi ọ̀rọ
wọnyi. Njẹ wá nisisiyi, ki a jọ gbimọ̀
pọ̀.
8 Nigbana ni mo ranṣẹ si i wipe, A kò
ṣe iru eyi, ti iwọ sọ, ṣugbọn iwọ rò wọn li
ọkàn ara rẹ ni.
9 Nitori gbogbo wọn mu wa bẹ̀ru, wipe,
Ọwọ wọn yio rọ ninu iṣẹ na, ki a má le ṣe
e. Njẹ nisisiyi, Ọlọrun, mu ọwọ mi le.
10 Mo si wá si ile Ṣemaiah ọmọ Delaiah
ọmọ Mehetabeeli, ti a há mọ, o si wipe, Jẹ
ki a pejọ ni ile Ọlọrun ni inu tempili ki a
si tì ilẹkùn tempili; nitori nwọn o wá lati
pa ọ; nitõtọ, li oru ni nwọn o wá lati
pa ọ.
11 Mo si wipe, Enia bi emi a ma sa?
Tali o si dabi emi, ti o jẹ wọ inu tempili lọ
lati gba ẹmi rẹ̀ lá? Emi kì yio wọ̀ ọ lọ.
12 Sa kiyesi i, mo woye pe, Ọlọrun kọ
rán a, ṣugbọn pe, o nsọ asọtẹlẹ yi si mi:
nitori Tobiah ati Sanballati ti bẹ̀ ẹ li ọ̀wẹ.
13 Nitorina li o ṣe bẹ̀ ẹ li ọ̀wẹ, ki emi
ba foya, ki emi ṣe bẹ̃, ki emi si ṣẹ̀, ki nwọn
le ri ihìn buburu rò, ki nwọn le kẹgán mi.
14 Ọlọrun mi, rò ti Tobiah ati Sanballa-
ti gẹgẹ bi iṣẹ wọn wọnyi, ati ti Noadiah,
woli obirin, ati awọn woli iyokù ti nwọn fẹ
mu mi bẹ̀ru,
15 Bẹ̃li a pari odi na li ọjọ kẹ̃dọgbọn
oṣù Eluli, ni ọjọ mejilelãdọta.
16 O si ṣe, nigbati gbogbo awọn ọta wa
gbọ́, gbogbo awọn keferi àgbegbe wa si
bẹ̀ru, nwọn si rẹ̀wẹsi pupọ li oju ara wọn,
nitori nwọn woye pe, lati ọwọ Ọlọrun wá li
a ti ṣe iṣẹ wọnyi.
17 Pẹlupẹlu li ọjọ wọnni, awọn ijòye
Juda ran iwe pupọ si Tobiah, iwe Tobiah
si de ọdọ wọn.
18 Nitori ọ̀pọlọpọ ni Juda ti ba a mulẹ
nitori ti o jẹ ana Sekaniah ọmọ Ara; ọmọ
rẹ̀ Johanani si ti fẹ ọmọ Meṣullamu, ọmọ
Berekiah.
19 Nwọn sọ̀rọ rere rẹ̀ pẹlu niwaju mi,
nwọn si sọ ọ̀rọ mi fun u. Tobiah rán iwe
lati da aiya fò mi.

Digitized by Google

## ORI 7.

OSI ṣe, nigbati a mọ odi na tan, ti mo si
gbe ilẹkùn ro, ti a si yan awọn oludena
ati awọn akọrin, ati awọn ọmọ Lefi,
2 Mo si fun Hanani arakọnrin mi, ati
Hananiah ijòye ãfin, li aṣẹ lori Jerusalemu:
nitori olododo enia li o ṣe, o si bẹru Ọlọrun
jù enia pupọ lọ.
3 Mo si wi fun wọn pe, Ẹ má jẹ ki ilẹkùn
odi Jerusalemu ṣi titi õrùn o fi mú;
bi nwọn si ti duro, jẹ ki wọn se ilẹkùn, ki
nwọn si há wọn, ki nwọn si yan ẹṣọ ninu
awọn ti ngbe Jerusalemu, olukuluku ninu
iṣọ rẹ̀, ati olukuluku ninu ile rẹ̀.
4 Ṣugbọn ilu na gbõrò, o si tobi, awọn
enia inu rẹ̀ si kere, a kò si kọ́ ile tan.
5 Ọlọrun mi si fi si mi li aiya lati ko
awọn ijòye jọ, ati awọn olori, ati awọn
enia, ki a le kà wọn nipa idile wọn. Mo
si ri iwe idile awọn ti o kọ́ goke wá, mo ri
pe, a kọ ọ sinu rẹ̀.
6 Wọnyi ni awọn ọmọ igberiko, ti o gòke
wá lati ìgbekun ninu awọn ti a ti ko lọ,
ti Nebukadnesari ọba Babiloni ti ko lọ, ti
nwọn tun padà wá si Jerusalemu, ati si
Juda, olukuluku si ilu rẹ̀.
7 Awọn ti o ba Serubbabeli wá, Jeṣua,
Nehemiah, Asariah, Raamiah, Nahamani,
Mordikai, Bilṣani, Mispereti, Bigfai, Nehumu,
Baana. Iye awọn ọkọnrin enia
Israeli li eyi;
8 Awọn ọmọ Paroṣi, ẹgbã o le mejilelãdọsan.
9 Awọn ọmọ Ṣefatiah, ojidinirinwo o le
mejila.
10 Awọn ọmọ Ara, adọtalelẹgbẹta o le
meji.
11 Awọn ọmọ Pahat-moabu, ti awọn
ọmọ Jeṣua, ati Joabu, ẹgbẹrinla o le mejidilogun.
12 Awọn ọmọ Elamu, ẹgbẹfa o le mẹrinlelãdọta.
13 Awọn ọmọ Sattu, ojilelẹgbẹrin o le
marun.
14 Awọn ọmọ Sakkai, ojidilẹgbẹrin.
15 Awọn ọmọ Binnui, ojilelẹgbẹta o le
mẹjọ.
16 Awọn ọmọ Bebai, ẹgbẹta o le mejidilọgbọn.
17 Awọn ọmọ Asgadi, egbejila o di mejidilọgọrin.
18 Awọn ọmọ Adonikamu ọtalelẹgbẹta
o le meje.
19 Awọn omọ Bigfai, ẹgbã o le mẹtadılãdọrin.
20 Awọn ọmọ Adini, ãdọtalelẹgbẹta o le
marun.
21 Awọn ọmọ Ateri, ti Hesekiah mejidilọgọrun.
22 Awọn ọmọ Haṣumu, ọrindinirinwo o
le mẹjọ.
23 Awọn ọmọ Besai, ọrindinirinwo o le
mẹrin.
24 Awọn ọmọ Harifu mejilelãdọfa.
25 Awọn ọmọ Gibioni, marundilọgọrun.
26 Awọn ọkọnrin Betlehemu ati Netofa,
ọgọsan o le mẹjọ.
27 Awọn ọkọnrin Anatoti, mejidilãdoje.
28 Awọn ọkọnrin Bet-asmafeti, mejilelogoji.
29 Awọn ọkọnrin Kiriat-jearimu, Kefira,
ati Beeroti, ọtadilẹgbẹrin o le mẹta,
30 Awọn ọkọnrin Rama ati Gaba, ẹgbẹta
o le mọkanlelogun.
31 Awọn ọkọnrin Mikmasi, mejilelọgọfa.
32 Awọn ọkọnrin Beteli ati Ai, mẹtalelọgọfa.
33 Awọn ọkọnrin Nebo miran mejilelãdọta.
34 Awọn ọmọ Elamu miran ẹgbẹfa o le
mẹrinlelãdọta.
35 Awọn ọmọ Harimu, ọrindinirinwo.
36 Awọn ọmọ Jeriko, ọtadinirinwo o le
marun.
37 Awọn ọmọ Lodi, Hadidi, ati Ono,
ọrindilẹgbẹrin o le ọkan.
38 Awọn ọmọ Senaah ẹgbãji o di ãdọrin.
39 Awọn alufa: awọn ọmọ Jedaiah ti
ile Jeṣua, ẹgbã o di mẹtadilọgbọn.
40 Awọn ọmọ Immeri, ẹgbẹrun o le mejilelãdọta.
41 Awọn ọmọ Paṣuri, ẹgbẹfa o le mẹtadiladọta.
42 Awọn ọmọ Harimu ẹgbẹrun o le mẹtadilogun.
43 Awọn ọmọ Lefi: awọn ọmọ Jeṣua, ti
Kadmieli, ninu ọmọ Hodafa, mẹrinlelãdọrin.
44 Awọn akọrin: awọn ọmọ Asafu, mejidilãdọjọ.
45 Awọn oludena: awọn ọmọ Ṣallumu,
awọn ọmọ Ateri, awọn ọmọ Talmoni, awọn
ọmọ Akkubu, awọn omo Hatita, awọn ọmọ
Ṣobai, mejidilogoje.
46 Awọn ọmọ Netinimu: awọn ọmọ
Siha, awọn ọmọ Haṣufa, awọn ọmọ Tabbaoti,
47 Awọn ọmọ Kerosi, awọn ọmọ Sia,
awọn ọmọ Padoni,
48 Awọn ọmọ Lebana, awọn ọmọ Hagaba,
awọn ọmọ Salmai,

Digitized by Google

49 Awọn ọmọ Hanani, awọn ọmọ Giddeli, awọn ọmọ Gahari,
50 Awọn ọmọ Reaiah, awọn ọmọ Resini, awọn ọmọ Nekoda.
51 Awọn ọmọ Gassamu, awọn ọmọ Ussa, awọn ọmọ Fasea,
52 Awọn ọmọ Besai, awọn ọmọ Meunimu, awọn ọmọ Nefiṣesimu,
53 Awọn ọmọ Bakbuku, awọn ọmọ Hakufa, awọn ọmọ Harhuri,
54 Awọn ọmọ Basliti, awon ọmọ Mehida, awọn ọmọ Harsa,
55 Awọn ọmọ Barkosi, awọn ọmọ Sisera, awọn ọmọ Tama,
56 Awọn ọmọ Nesia, awọn ọmọ Hatifa.
57 Awọn ọmọ awọn iranṣẹ Solomoni: awọn ọmọ Sotai, awọn ọmọ Sofereti, awọn ọmọ Perida,
58 Awọn ọmọ Jaala, awọn ọmọ Darkoni, awọn ọmọ Giddeli.
59 Awọn ọmọ Ṣefatiah, awọn ọmọ Hattili, awọn ọmọ Pokereti ti Sebaimu, awọn ọmọ Amoni.
60 Gbogbo awọn Netinimu, ati awọn ọmọ awọn iranṣẹ Solomoni jẹ irinwo din mẹjọ.
61 Awọn wọnyi li o si goke lati Telhariṣa, Kerubu, Addoni, ati Immeri wá: ṣugbọn nwọn kò le fi ile baba wọn hàn, tabi iran wọn, bi nwọn iṣe ti Israeli.
62 Awọn ọmọ Delaiah, awọn ọmọ Tobiah, awọn ọmọ Nekoda, ojilelẹgbẹta o le meji.
63 Ati ninu awọn alufa: awon ọmọ Habaiah, awọn ọmọ Kosi, awọn ọmọ Barsillai, ti o ni ọkan ninu awọn ọmọbirin Barsillai, ara Gileadi, li aya, a si npè e nipa orukọ wọn.
64 Awọn wọnyi wá iwe orukọ wọn ninu awọn wọnyi ti a kọ orukọ wọn nipa idile, ṣugbọn a kò ri i: nitorina li a ṣe yà wọn kurò ninu oyè alufa.
65 Bãlẹ na si wi fun wọn pe, ki nwọn máṣe jẹ ninu ohun mimọ́ julọ, titi alufa kan yio fi duro pẹlu Urimu, ati Tummimu,
66 Iye gbogbo ijọ jasi ẹgbãmọkanlelogun o le ojidinirinwo.
67 Laikà awọn iranṣẹ-kọnrin wọn ati iranṣẹ-birin wọn, iye wọn jẹ ẹgbẹtadilẹgbãrin o di ẹtalelọgọta: nwọn si ni ojilugba o le marun akọni ọkọnrin ati akọni obirin,
68 Ẹṣin wọn jẹ ọtadilẹgbẹrin o di mẹrin: ibaka nwọn jẹ ojilugba o le marun:
69 Rakumi jẹ ojilenirinwo o di marun: kẹtẹkẹtẹ jẹ ẹgbẹrinlelọgbọn o di ọgọrin.
70 Omiran ninu awọn olori ninu awọn baba fi nkan si iṣẹ na. Bãlẹ fi ẹgbẹrun dramu wura, ãdọta awokoto, ọrindilẹgbẹta le mẹwa ẹwu alufa sinu iṣura na.
71 Ninu awọn olori ninu awọn baba fi ọkẹ meji dramu wura, ati ọgbọkanla mina fadaka si iṣura iṣẹ na.
72 Ati eyiti awọn enia iyokù mu wá jẹ ọkẹ meji dramu wura, ati ẹgbã mina fadaka, ati ẹwu alufa mẹtadilãdọrin.
73 Bẹ̃ni awọn alufa, ati awọn ọmọ Lefi, ati awọn oludena, ati awọn akọrin, ati ninu awọn enia, ati awọn Netinimu, ati gbogbo Israeli, ngbe ilu wọn; nigbati oṣu keje si pé, awọn ọmọ Israeli wà ni ilu wọn.

## ORI 8.

NIGBANA ni gbogbo awọn enia ko ara wọn jọ bi enia kan si ita ti o wà niwaju ẹnu-bode omi; nwọn si sọ fun Esra akọwe lati mu iwe ofin Mose wá, ti Oluwa ti paṣẹ fun Israeli.
2 Esra alufa si mu ofin na wá iwaju ijọ t'ọkọnrin t'obirin, ati gbogbo awọn ti o le fi oye gbọ́, li ọjọ kini oṣu ekeje.
3 O si kà ninu rẹ̀ niwaju ita ti o wà niwaju ẹnu-bode omi lati owurọ titi di idaji ọjọ, niwaju awọn ọkọnrin ati awọn obirin, ati awọn ti o le ye; gbogbo enia si tẹtisilẹ si iwe ofin.
4 Esra akọwe si duro lori aga iduro sọ̀rọ, ti nwọn ṣe nitori eyi na: lẹba ọdọ rẹ̀ ni Mattitiah si duro, ati Ṣema, ati Anaiah, ati Urijah, ati Hilkiah, ati Maaseiah, li ọwọ ọtun rẹ̀; ati li ọwọ òsi rẹ̀ ni Pedaiah, ati Miṣaeli, ati Malkiah, ati Haṣumu, ati Haṣbadana, Sekariah, ati Meṣullamu.
5 Esra si ṣi iwe na li oju gbogbo enia; (nitori on ga jù gbogbo enia) nigbati o si ṣi i, gbogbo enia dide duro:
6 Esra si fi ibukun fun Oluwa Ọlọrun, ti o tobi. Gbogbo enia si dahun pe, Amin, Amin! pẹlu gbigbe ọwọ wọn soke: nwọn si tẹ̀ ori wọn ba, nwọn si sìn Oluwa ni idojubò ilẹ.
7 Jeṣua pẹlu ati Bani, ati Ṣerebiah, Jamini, Akkubu, Ṣabbetai, Hodijah, Maaseiah, Kelita, Asariah, Josabadi, Hanani, Pelaiah, ati awọn ọmọ Lefi, mu ki ofin ye awọn enia: awọn enia si duro ni ipò wọn.
8 Bẹ̃ni nwọn kà ninu iwe ofin Ọlọrun ketekete, nwọn tumọ rẹ̀, nwọn si mu ki iwe kikà na ye wọn.
9 Ati Nehemiah ti iṣe bãlẹ, ati Esra alufa, akọwe, ati awọn ọmọ Lefi, ti o kọ́ awọn enia wi fun gbogbo enia pe, Ọjọ yi jẹ mimọ́ fun Oluwa Ọlọrun nyin; ẹ má

Digitized by Google

ọ ki ẹ má si sọkún. Nitori gbogbo
ọn enia sọkún, nigbati nwọn gbọ́ ọ̀rọ
ı.
0 Nigbana ni o wi fun wọn pe, Ẹ lọ, ẹ
ọ̀ra ki ẹ si mu ohun didùn, ki ẹ si fi
kan ipin ranṣẹ si awọn ti a kò pèse fun:
ọri mimọ́ ni ọjọ yi fun Oluwa: ẹ máṣe
ıujẹ; nitori ayọ̀ Oluwa on li agbara
n.
1 Bẹ̃ni awọn ọmọ Lefi mu gbogbo enia
:ẹ jẹ, wipe, ẹ dakẹ, nitori mimọ́ ni ọjọ
ẹ má si ṣe banujẹ.
2 Gbogbo awọn enia lọ lati jẹ ati lati
ati lati fi ipin ranṣẹ, ati lati yọ ayọ̀ nla,
ọriti ọ̀rọ ti a sọ fun wọn ye wọn.
3 Li ọjọ keji awọn olori awọn baba
ıgbo awọn enia, awọn alufa, ati awọn
ọ Lefi pejọ si ọdọ Esra akọwe, ki o le fi
ofin ye wọn.
4 Nwọn si ri a kọ sinu iwe-ofin, ti
ıwa ti pa li aṣẹ nipa ọwọ Mose pe, ki
ọn ọmọ Israeli gbe inu agọ ni àse oṣu
e:
5 Pe, ki nwọn funrere, ki nwọn kede
gbogbo ilu wọn, ati ni Jerusalemu, wipe,
jade lọ si òke, ki ẹ si mu ẹka igi olifi,
igi pine, ati ẹka igi matili (myrtle)
ọ ọpẹ, ati ẹka igi ti o tobi, lati ṣe agọ
ẹ bi a ti kọ ọ.
6 Bẹ̃ni awọn enia na jade lọ, nwọn si
wọn wá, nwọn pa agọ fun ara wọn,
kuluku lori orule ile rẹ̀, ati li àgbala
ı, ati li àgbala ile Ọlọrun, ati ni ita
ı-bode omi, ati ni ita ẹnu-bode Efraimu.
7 Gbogbo ijọ enia ninu awọn ti o pada
lati oko-ẹrú si pa agọ, nwọn si gbe abẹ
ọn agọ na: nitori lati akokò Jeṣua ọmọ
ni wá, titi di ọjọ na awọn ọmọ Israeli
ṣe bẹ̃. Ayọ̀ nlanla si wà.
8 Esra si kà ninu iwe ofin Ọlọrun li
jumọ, lati ọjọ kini titi de ọjọ ikẹhin.
ọn si pa àse na mọ li ọjọ meje, ati lọjọ
ọ, nwọn ni apejọ ti o ni ìronu gẹgẹ bi
wọn.

ORI 9.

I ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi, awọn ọmọ
Israeli pejọ ninu àwẹ ati aṣọ ọ̀fọ, ati
pẹ lori wọn.
2 Awọn iru-ọmọ Israeli si ya ara wọn
o ninu awọn ọmọ alejo, nwọn si duro,
ọn jẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn, ati aiṣedede awọn baba
n.
3 Nwọn si dide duro ni ipò wọn, nwọn
i idamẹrin ọjọ kà ninu iwe ofin Oluwa
Ọlọrun wọn; nwọn si fi idamẹrin jẹwọ,
nwọn si sìn Oluwa Ọlọrun wọn.
4 Nigbana ni Jeṣua, ati Bani, Kadmieli,
Ṣebaniah, Bunni, Ṣerebiah, Bani ati Ke-
nani duro lori pẹtẹsì awọn ọmọ Lefi, nwọn
si fi ohùn rara kigbe si Oluwa Ọlọrun wọn.
5 Awọn ọmọ Lefi Jeṣua, Kadmieli, Bani,
Haṣabaiah, Ṣerebiah, Hodijah, Sebaniah,
ati Pelaniah, si wipe: Ẹ dide, ki ẹ fi iyìn
fun Oluwa Ọlọrun nyin lai ati lailai: ibu-
kun si ni fun orukọ rẹ ti o li ogo, ti o ga
jù gbogbo ibukun ati iyìn lọ.
6 Iwọ, ani iwọ nikanṣoṣo li Oluwa; iwọ
li o ti dá ọrun, ọrun awọn ọrun pẹlu gbogbo
ogun wọn, aiye, ati ohun gbogbo ti mbẹ
ninu rẹ̀, okun, ati ohun gbogbo ti mbẹ̀
ninu rẹ̀, iwọ si pa gbogbo wọn mọ́ lãyè,
ogun ọrun si nsìn ọ.
7 Iwọ ni Oluwa Ọlọrun, ti o ti yan
Abramu, ti o si mu u jade lati Uri ti
Kaldea wá, iwọ si sọ orukọ rẹ̀ ni Abra-
hamu;
8 Iwọ si ri pe ọkàn rẹ̀ jẹ olõtọ niwaju rẹ,
iwọ si ba a dá majẹmu lati fi ilẹ awọn ara
Kenaani, awọn ara Hitti, awọn ara Amori,
ati awọn ara Perisi, ati awọn ara Jebusi,
ati awọn ara Girgaṣi fun u, lati fi fun iru-
ọmọ rẹ̀, iwọ si ti mu ọ̀rọ rẹ ṣẹ: nitori
olododo ni iwọ:
9 Iwọ si ri ipọnju awọn baba wa ni
Egipti, o si gbọ́ igbe wọn lẹba Okun Pupa;
10 O si fi ami, ati iṣẹ-iyanu hàn li ara
Farao, ati li ara gbogbo iranṣẹ rẹ̀, ati li
ara gbogbo enia ilẹ rẹ̀: nitori iwọ mọ̀ pe,
nwọn hu ìwa igberaga si wọn. Iwọ si fi
orukọ fun ara rẹ bi ti oni yi.
11 Iwọ si ti pin okun niwaju wọn, nwọn
si la arin okun ja li ori ilẹ gbigbẹ; iwọ
sọ awọn oninunibini wọn sinu ibú, bi okuta
sinu omi lile.
12 Iwọ si fi ọwọ̀n awọsanma ṣe amọ̀na
wọn li ọsan, ati li oru, ọwọ̀n iná, lati
fun wọn ni imọlẹ li ọ̀na ninu eyiti nwọn
o rin.
13 Iwọ si sọkalẹ wá si ori òke Sinai,
o si bá wọn sọ̀rọ lati ọrun wá, o fun wọn
ni idajọ titọ, ofin otitọ, ilana ati ofin rere.
14 Iwọ si mu ọjọ isimi mimọ rẹ di mimọ̀
fun wọn, o si paṣẹ ẹkọ́, ilana, ati ofin fun
wọn, nipa ọwọ Mose iranṣẹ rẹ.
15 O si fun wọn li onjẹ lati ọrun wá
fun ebi wọn, o si mu omi lati inu apata
wá fun ọrungbẹ wọn, o si ṣe ileri fun wọn
pe, ki nwọn lọ ijogun ilẹ na ti iwọ ti bura
lati fi fun wọn.
16 Ṣugbọn awọn ati awọn baba wa hu

Digitized by Google

ìwa ìgberaga, nwọn si mu ọrùn wọn le, nwọn kò si gba ofin rẹ gbọ́.

17 Nwọn si kọ̀ lati gbọràn, bẽni nwọn kò ranti iṣẹ iyanu ti iwọ ṣe li ãrin wọn; ṣugbọn nwọn mu ọrùn wọn le, ninu ìṣọtẹ wọn, nwọn yan olori lati pada si oko-ẹrú wọn: ṣugbọn iwọ li Ọlọrun ti o mura lati dariji, olore ọfẹ, ati alãnu, o lọra lati binu, o si ṣeun pipọ̀; o kò si kọ̀ wọn silẹ.

18 Nitõtọ nigbati nwọn ṣe ẹgbọrọmalu didà, ti nwọn si wipe, Eyi li Ọlọrun rẹ ti o mu ọ gòke ti Egipti jade wá, nwọn si ṣe imunibinu nla.

19 Ṣugbọn iwọ, ninu ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ, kò kọ̀ wọn silẹ li aginju, ọwọ̀n kũkũ kò kuro lọdọ wọn lojojumọ lati ṣe amọna wọn, bẽ si li ọwọ̀n iná lati fun wọn ni imọlẹ li oru li ọ̀na ti nwọn iba rìn.

20 Iwọ fun wọn li ẹmi rere rẹ pẹlu lati kọ́ wọn, iwọ kò si gba manna rẹ kuro li ẹnu wọn, iwọ si fun wọn li omi fun ọrungbẹ wọn.

21 Nitotọ, ogoji ọdun ni iwọ fi bọ́ wọn li aginju, nwọn kò si ṣe alaini; aṣọ wọn kò gbó, ẹsẹ wọn kò si wú.

22 Pẹlupẹlu iwọ fi ijọba ati orilẹ-ède fun wọn, o si pin wọn si ìha gbogbo, bẽni nwọn jogun ilẹ Sihoni, ati ilẹ ọba Heṣboni, ati ilẹ Ogu, ọba Baṣani.

23 Awọn ọmọ wọn pẹlu ni iwọ sọ di pipọ bi irawọ ọrun, o si mu wọn wá ilẹ na sipa eyiti o ti leri fun awọn baba wọn pe: ki nwọn lọ sinu rẹ̀ lati gbà a.

24 Bẽli awọn ọmọ na wọ inu rẹ̀ lọ, nwọn si gbà ilẹ na, iwọ si tẹ ori awọn ara ilẹ na ba niwaju wọn, awọn ara Kenaani, o si fi wọn le ọwọ wọn, pẹlu ọba wọn, ati awọn enia ilẹ na, ki nwọn o ki le fi wọn ṣe bi o ti wù wọn.

25 Nwọn si gbà ilu alagbara, ati ilẹ ọlọra, nwọn si gbà ilẹ ti o kún fun ohun rere, kanga, ọgba-ajara, ọgba-olifi, ati igi eleso, li ọ̀pọlọpọ: bẽni nwọn jẹ, nwọn si yo, nwọn sanra, nwọn si ni inudidùn ninu ore rẹ nla.

26 Ṣugbọn nwọn ṣe alaigbọràn, nwọn si ṣọ̀tẹ si ọ, nwọn si gbe ofin rẹ sọ si ẹ̀hin wọn, nwọn si pa awọn woli rẹ ti nsọ fun wọn lati yipada si ọ, nwọn si ṣe imunibinu nla.

27 Nitorina ni iwọ fi wọn le ọwọ awọn ọta wọn, ti o pọn wọn loju, ati li akoko iponju wọn, nigbati nwọn kigbe pè ọ, iwọ gbọ́ lati ọrun wá; ati gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ, iwọ fun wọn li olugbala, ti nwọn gbà wọn kuro lọwọ awọn ọta wọn.

28 Ṣugbọn li ẹhin ti nwọn ni isimi, nwọn si tun ṣe buburu niwaju rẹ: nitorina ni iwọ fi wọn le ọwọ awọn ọta wọn, tobẽ ti nwọn jọba li ori wọn: ṣugbọn nigbati nwọn pada, ti nwọn si kigbe pè ọ, iwọ gbọ́ lati ọrun wá, ọ̀pọlọpọ igba ni iwọ si gbà wọn gẹgẹ bi ãnu rẹ.

29 Iwọ si jẹri gbè wọn ki iwọ ki o le tun mu wọn wá sinu ofin rẹ, ṣugbọn nwọn hu ìwa igberaga, nwọn kò si fi eti si ofin rẹ, nwọn si ṣẹ̀ si idajọ rẹ (eyiti bi enia ba ṣe on o yè ninu wọn), nwọn si gún ẹ̀jika, nwọn mu ọrùn wọn le, nwọn kò si fẹ igbọ́.

30 Sibẹ ọ̀pọlọpọ ọdun ni iwọ fi mu suru fun wọn ti o si fi ẹmi rẹ jẹri gbè wọn ninu awọn woli rẹ: sibẹ̀ nwọn kò fi eti silẹ: nitorina ni iwọ ṣe fi wọn le ọwọ awọn enia ilẹ wọnni.

31 Ṣugbọn nitori ãnu rẹ nla iwọ kò run wọn patapata, bẽni iwọ kọ kọ̀ wọn silẹ; nitori iwọ li Ọlọrun olore-ọfẹ ati alãnu.

32 Njẹ nitorina, Ọlọrun wa, Ọlọrun ti o tobi, ti o li agbara, ti o si li ẹ̀ru, ẹniti npa majẹmu ati ãnu mọ, má jẹ ki gbogbo iyọnu na dabi ohun kekere niwaju rẹ, o de bá wa, awọn oba wa, awọn ijoye wa, ati awọn alufa wa, ati awọn woli wa, ati awọn baba wa, ati gbogbo awọn enia rẹ lati akoko ọba Assiria wá, titi o fi di oni yi.

33 Sibẹ, iwọ ṣe olododo ninu ohun gbogbo ti o de ba wa, iwọ si ti ṣe otitọ, ṣugbọn awa ti ṣe buburu:

34 Awọn ọba wa, awọn ijoye wa, awọn alufa wa, ati awọn baba wa, kò pa ofin rẹ mọ, bẽni nwọn kò fi eti si aṣẹ rẹ, ati ẹri rẹ, ti iwọ fi jẹri gbè wọn.

35 Nitori ti nwọn kò sìn ọ ninu ijọba wọn, ati ninu ore rẹ nla ti iwọ fi fun wọn, ati ninu ilẹ nla ati ọlọra ti o fi si iwaju wọn, bẽni nwọn kò pada kuro ninu iṣẹ buburu wọn.

36 Kiyesi i, ẹrú li awa iṣe li oni yi, ati ilẹ ti iwọ fi fun awọn baba wa lati ma jẹ eso rẹ̀, ati ire rẹ̀, kiyesi i, awa jẹ ẹrú ninu rẹ̀.

37 Ilẹ na si mu ohun ọ̀pọlọpọ wá fun awọn ọba, ti iwọ ti fi ṣe olori wa nitori ẹ̀ṣẹ wa: nwọn ni aṣẹ lori ara wa pẹlu, ati lori ẹran-nla wa, bi o ti wù wọn, awa si wà ninu wàhala nla.

38 Ati nitori gbogbo eyi awa dá majẹmu ti o daju, o si kọwe rẹ̀; awọn ìjoye wa, awọn ọmọ Lefi, ati awọn alufa si fi ẹ̀didi di i.

Digitized by Google

## ORI 10.

)N ti o fi èdidi di i ni Nehemiah,
ıālẹ, ọmọ Hakaliah, ati Sidkijah.
eraiah, Asariah, Jeremiah,
'aṣuri, Amariah, Malkijah,
Iattuṣi, Ṣebaniah, Malluki,
Iarimu, Meremoti, Obadiah,
)anieli, Ginnetoni, Baruki,
Ieṣullamu, Abijah, Mijamini,
Iaaṣiah, Bilgai, Ṣemaiah: alufa li
wọnyi.
Ati awọn ọmọ Lefi: ati Jeṣua ọmọ
iah, Binnui, ọkan ninu awọn ọmọ
dadi, Kadmieli;
Ati awọn arakọnrin wọn, Ṣebaniah,
jah, Kelita, Pelaiah, Hanani,
Mika, Rehobu, Haṣabiah,
Sakkuri, Ṣerebiah, Ṣebaniah,
Hodijah, Bani, Beninu.
Awọn olori awọn enia; Paroṣi, Pa-
moabu, Elamu, Sattu, Bani.
Bunni, Asgadi, Bebai,
Adonijah, Bigfai, Adini,
Ateri, Hiskijah, Assuri,
Hodijah, Haṣumu, Besai,
Harifi, Anatoti, Nebai,
Magpiaṣi Meṣullamu Hasiri,
Meṣesabeeli, Sadoku, Jaddua,
! Pelatiah, Hanani, Anaiah,
; Hoṣea, Hananiah, Haṣubu,
Halloheṣi, Pileha, Ṣobeki,
Rehumu, Hasabna Maaseiah,
Ati Ahijah, Hanani, Anani,
Malluku, Harimu, Baana.
3 Ati awọn enia iyokù, awọn alufa,
n ọmọ Lefi, awọn adèna, awọn akọrin,
n Netinimu, ati gbogbo awọn ti o ya
wọn kuro lọdọ awọn enia ilẹ na si ofin
run, aya wọn, awọn ọmọ wọn ọkọnrin,
awọn ọmọ wọn obirin, gbogbo ẹniti
ìmọ ati oye;
9 Nwọn faramọ awọn arakọnrin wọn,
ın ijoye wọn, nwọn si wọ inu èpe ati
ra, lati ma rìn ninu ofin Ọlọrun, ti a fi
nipa ọwọ Mose iranṣẹ Ọlọrun, lati ki-
i, ati lati ṣe gbogbo aṣẹ Jehofah, Oluwa
ati idajọ rẹ̀, ati ilana rẹ̀;
30 Ati pe awa kì yio fi awọn ọmọbirin
fun awọn enia ilẹ na, bẹ̀li awa kì yio fẹ
ọbirin wọn fun awọn ọmọ wa.
31 Bi awọn enia ilẹ na ba mu ọjà tabi
ın jijẹ wa li ọjọ isimi lati tà, awa kì yio
a li ọwọ wọn li ọjọ isimi, tabi li ọjọ
mọ́: awa o si fi ọdun keje silẹ, ati ifi-
bara-gba gbèse.

32 Awa si ṣe ilàna fun ara wa pe, ki
olukuluku ma san idamẹta ṣekeli li ọdọdun
fun iṣẹ ile Ọlọrun wa.
33 Nitori àkara ifihàn, ati nitori ẹbọ
ohun jijẹ igbagbogbo, ati nitori ẹbọ sisun
igbagbogbo, ti ọjọ isimi, ti oṣù titun, ti
àse ti a yàn, ati nitori ohun mimọ́, ati ni-
tori ẹbọ ẹ̀ṣẹ lati ṣe ètutu fun Israeli, ati fun
gbogbo iṣẹ ile Ọlọrun wa.
34 Awa si dìbo larin awọn alufa awọn
ọmọ Lefi, ati awọn enia, fun ọrẹ igi, lati
mu u wá si ile Ọlọrun wa, gẹgẹ bi idile
awọn baba wa li akoko ti a yàn li ọdọdun,
lati fi daná li ori pẹpẹ Oluwa Ọlọrun wa,
gẹgẹ bi a ti kọ ọ ninu ofin.
35 Ati lati mu akọso ilẹ wa wá, ati gbo-
gbo akọso eso igi gbogbo, li ọdọdun si ile
Oluwa wa:
36 Pẹlu akọbi awọn ọmọ wa ọkọnrin, ati
ti ohun ọ̀sin wa, gẹgẹ bi ati kọ ninu ofin,
akọbi awọn ẹran-nla wa, ati ti agutan wa,
lati mu wọn wá si ile Ọlọrun wa, fun awọn
alufa ti nṣiṣẹ ni ile Ọlọrun wa.
37 Ki awa si mu akọso iyẹfun pipò wa
wá, ati ọrẹ wa, ati eso oniruru igi wa, ti
ọti-waini ati ti ororo fun awọn alufa, si
iyẹwu ile Ọlọrun wa, ati idamẹwa ilẹ wa
fun awọn ọmọ Lefi, ki awọn ọmọ Lefi ki
o le ni idamẹwa ninu gbogbo ilu arọko
wa.
38 Alufa ọmọ Aaroni yio si wà pẹlu awọn
ọmọ Lefi, nigbati awọn ọmọ Lefi yio gba
idamẹwa: awọn ọmọ Lefi yio si mu ida-
mẹwa ti idamẹwa na wá si ile Ọlọrun wa,
sinu iyẹwu, sinu ile iṣura.
39 Nitori awọn ọmọ Israeli ati awọn
ọmọ Lefi ni yio mu ọrẹ ọkà wá, ti ọti-waini
titun, ati ororo, sinu iyẹwu, nibiti ohun-
èlo ibi mimọ́ gbe wà, ati awọn alufa ti
nṣiṣẹ, ati awọn adèna, ati awọn akọrin:
awa kì yio si kọ̀ ile Ọlọrun wa silẹ.

## ORI 11.

AWỌN olori awọn enia si ngbe Jerusa-
lemu: awọn enia iyokù si dìbo lati
mu ẹnikan ninu ẹnimẹwa lati ma gbe Je-
rusalemu, ilu mimọ́, ati mẹsan iyokù lati
ma gbe ilu miran.
2 Awọn enia si sure fun gbogbo awọn
ọkọnrin na ti nwọn yan ara wọn lati gbe
Jerusalemu.
3 Wọnyi si ni awọn olori igberiko ti
ngbe Jerusalemu, ṣugbọn ninu ilu Juda,
olukuluku ngbe inu ilẹ ìni rẹ̀ ninu ilu wọn,
eyini ni: awọn ọmọ Israeli, awọn alufa, ati

Digitized by Google

awọn ọmọ Lefi, ati awọn Netinimu, ati awọn ọmọ awọn iranṣẹ Solomoni.

4 Ati ninu awọn ọmọ Juda ngbe Jerusalemu, ati ninu awọn ọmọ Benjamini. Ninu awọn ọmọ Juda, Ataiah ọmọ Ussiah, ọmọ Sekariah, ọmọ Amariah, ọmọ Ṣefatiah, ọmọ Mahalaleeli, ninu awọn ọmọ Péresi ;

5 Ati Maaseiah ọmọ Baruku, ọmọ Kolhose, ọmọ Hạsaiah, ọmọ Adaiah, ọmọ Joiaribu, ọmọ Sekariah, ọmọ Ṣiloni.

6 Gbogbo ọmọ Peresi ti ngbe Jerusalemu jẹ adọrinlenirinwo o di meji, alagbara ọkọnrin.

7 Wọnyi li awọn ọmọ Benjamini ; Sallu ọmọ Meṣullamu ọmọ Joedi, ọmọ Pedaiah, ọmọ Kolaiah, ọmọ Maaseiah, ọmọ Itieli, ọmọ Jesaiah.

8 Ati lẹhin rẹ̀ Gabbai, Sallai, ọrindilẹgbẹrun o le mẹjọ.

9 Joeli ọmọ Sikri si ni alabojuto wọn ; ati Juda ọmọ Senua ni ibikeji ni ilu.

10 Ninu awọn alufa: Jedaiah ọmọ Joiaribu, Jakini.

11 Seraiah ọmọ Hilkiah, ọmọ Meṣullamu, ọmọ Sadoku, ọmọ Meraioti, ọmọ Ahitibu, ni olori ile Ọlọrun.

12 Awọn arakọnrin wọn ti o ṣe iṣẹ ile na jẹ, ẹgbẹrin o le mejilelogun: ati Adaiah ọmọ Jerohamu, ọmọ Pelaliah, ọmọ Amsi, ọmọ Sekariah, ọmọ Paṣuri, ọmọ Malkiah,

13 Ati awọn arakọnrin rẹ̀, awọn olori awọn baba, ojilugba o le meji: ati Amaṣai ọmọ Asareeli, ọmọ Ahasai, ọmọ Meṣillemoti, ọmọ Immeri,

14 Ati awọn arakọnrin wọn, alagbara li ogun, mejidilãdoje: ati olori wọn ni Sabdieli ọmọ ọkan ninu awọn enia nla.

15 Ninu awọn ọmọ Lefi pẹlu: Ṣemaiah, ọmọ Haṣubu, ọmọ Asrikamu, ọmọ Haṣabiah, ọmọ Bunni ;

16 Ati Ṣabbetai ati Josabadi, ninu olori awọn ọmọ Lefi ni alabojuto iṣẹ ode ile Ọlọrun.

17 Ati Mattaniah ọmọ Mika, ọmọ Sabdi, ọmọ Asafu, ni olori lati bẹrẹ idupẹ ninu adura: ati Bakbukiah ẹnikeji ninu awọn arakọnrin rẹ̀, ati Abda ọmọ Ṣammua, ọmọ Galali, ọmọ Jedutuni.

18 Gbogbo awọn ọmọ Lefi ninu ilu mimọ́ jẹ ọrinlugba o le mẹrin.

19 Ati awọn adèna, Akkubu, Talmoni, ati awọn arakọnrin wọn ti nṣọ ẹnu-ọ̀na jẹ mejilelãdọsan.

20 Ati iyokù Israeli, ti awọn alufa, ati ti awọn ọmọ Lefi, wà ni gbogbo ilu Juda, olukuluku ninu ilẹ ìni rẹ̀.

21 Ṣugbọn awọn Netinimu ngbe Ofeli: ati Siha, ati Gispa wà li olori awọn Netinimu.

22 Ati alabojuto awọn ọmọ Lefi ni Jerusalemu ni Ussi ọmọ Bani, ọmọ Haṣabiah, ọmọ Mattaniah, ọmọ Mika. Ninu awọn ọmọ Asafu, awọn akọrin wà lori iṣẹ ile Ọlọrun.

23 Nitori o jẹ aṣẹ ọba nipa ti wọn, pe ki ipin kan ti o yẹ ki o jẹ ti awọn akọrin, li ojojumọ.

24 Ati Petahiah ọmọ Meṣesabeeli ninu awọn ọmọ Serah ọmọ Juda, wà li ọwọ ọba ninu gbogbo awọn enia.

25 Ati fun ileto, pẹlu oko wọn, ninu awọn ọmọ Juda ngbe Kirjat-arba, ati ileto rẹ̀, ati ni Diboni, ati ileto rẹ̀, ati ni Jekabseeli, ati ileto rẹ̀,

26 Ati ni Jeṣua, ati ni Molada, ati ni Bet-feleti,

27 Ati ni Hasar-ṣuali, ati ni Beerṣeba, ati ileto rẹ̀,

28 Ati ni Siklagi, ati ni Mekona, ati ninu ileto rẹ̀,

29 Ati ni En-rimmoni, ati ni Sarea, ati Jarmuti,

30 Sanoa, Adullamu, ati ileto wọn, ni Lakiṣi, ati oko rẹ̀, ni Aseka, ati ileto rẹ̀. Nwọn si ngbe lati Beerṣeba titi de afonifoji Hinnomu.

31 Ati awọn ọmọ Benjamini lati Geba de Mikmaṣi, ati Aija, ati Beteli, ati ileto wọn.

32 Ni Anatotu, Nobu, Ananiah,

33 Hasori, Rama, Gittaimu,

34 Hadidi, Seboimu, Neballati,

35 Lodi, ati Ono, afonifoji awọn oniṣọnà,

36 Ati ninu awọn ọmọ Lefi, ipinya Juda si ngbe ilẹ Benjamini.

## ORI 12.

WỌNYI si ni awọn alufa ati awọn ọmọ Lefi ti o ba Serubbabeli ọmọ Ṣealtieli goke lọ, ati Jeṣua: Seraiah Jeremiah, Esra,

2 Amariah, Malluki, Hattuṣi,

3 Ṣekaniah, Rehumu, Meremoti,

4 Iddo, Ginneto, Abijah,

5 Miamini, Maadiah, Bilga,

6 Ṣemaiah, ati Joiaribu, Jodaiah,

7 Sallu, Amoku, Hilkiah, Jedaiah. Wọnyi li olori awọn alufa, ati ti awọn arakọnrin wọn li ọjọ Jeṣua.

8 Ati awọn ọmọ Lefi: Jeṣua, Binnui, Kadmieli, Ṣerebiah, Juda, ati Mattaniah,

Digitized by Google

ti o wà lori orin idupẹ, on ati awọn ara-
kọnrin rẹ̀.
9 Bakbukiah pẹlu ati Unni, awọn ara-
kọnrin wọn, li o kọju si wọn ninu iṣọ.
10 Jeṣua si bi Joiakimu, Joiakimu si bi
Eliaṣibu, Eliaṣibu si bi Joiada,
11 Joiada si bi Jonatani, Jonatani si bi
Jaddua.
12 Ninu awọn alufa li ọjọ Joiakimu li
awọn olori awọn baba wà: ti Seraiah,
Meraiah; ti Jeremiah, Hananiah;
13 Ti Esra, Meṣullamu; ti Amariah,
Jehohanani;
14 Ti Meliku, Jonatani; ti Ṣebaniah,
Josefu;
15 Ti Harimu, Adna; ti Meraioti
Helkai;
16 Ti Iddo, Sekariah; ti Ginnetoni,
Meṣullamu;
17 Ti Abijah, Sikri; ti Miniamini, ti
Moadiah Piltai:
18 Ti Bilga, Sammua; ti Ṣemaiah,
Jehonatani;
19 Ati ti Joaribu, Mattenai; ti Jedaiah,
Ussi;
20 Ti Sallai, Killai; ti Amoku, Eberi;
21 Ti Hilkiah, Haṣhabiah; ti Jedaiah,
Netaneeli;
22 Ninu awọn ọmọ Lefi li ọjọ Eliaṣibu,
Joiada, ati Johanani, ati Jaddua, awọn
olori awọn baba: li a kọ sinu iwe pẹlu
awọn alufa, titi di ijọba Dariusi ara Perṣia.
23 Awọn ọmọ Lefi, olori awọn baba li a
kọ sinu iwe itan titi di ọjọ Johanani ọmọ
Eliaṣibu.
24 Awọn olori awọn ọmọ Lefi si ni Haṣa-
biah, Ṣerebiah, ati Jeṣua ọmọ Kadmieli,
pẹlu awọn arakọnrin wọn kọju si ara wọn,
lati yìn ati lati dupẹ, gẹgẹ bi aṣẹ Dafidi
enia Ọlọrun, li ẹgbẹgbẹ ẹṣọ.
25 Mattaniah, ati Bakbukiah, Obadiah,
Meṣullamu, Talmoni, Akkubu, jẹ adèna
lati ma ṣọ iloro ẹnu-ọ̀na.
26 Wọnyi wà li ọjọ Joiakimu, ọmọ
Jeṣua, ọmọ Josadaki, ati li ọjọ Nehemiah
bãlẹ, at Esra alufa, ti iṣe akọwe.
27 Ati nigba yiya odi Jerusalemu si
mimọ́, nwọn wá awọn ọmọ Lefi kiri ninu
gbogbo ibugbe wọn, lati mu wọn wá si
Jerusalemu lati fi ayọ̀ ṣe iyà si mimọ́ na
pẹlu idupẹ ati orin, pẹlu simbali, psalteri,
ati pẹlu duru.
28 Awọn ọmọ awọn akọrin si ko ara
wọn jọ lati pẹtẹlẹ yi Jerusalemu ka, ati lati
ileto Netofati wá;
29 Lati ile Gilgali wá pẹlu, ati lati inu
ilẹ Geba ati Asmafeti, nitori awọn akọrin ti
kọ́ ileto fun ara wọn yi Jerusalemu kakiri.
30 Ati awọn alufa ati awọn ọmọ Lefi wẹ̀
ara wọn mọ́, nwọn si wẹ̀ awọn enia mọ́, ati
ẹnu-bode, ati odi.
31 Nigbana ni mo mu awọn ijoye Juda
wá si ori odi, mo si yàn ẹgbẹ nla meji, ninu
awọn ti ndupẹ, ẹgbẹ kan lọ si apa ọtun li
ori odi, siha ẹnu-bode àtan.
32 Hoṣaiah si lọ tẹle wọn ati idaji awọn
ijoye Juda.
33 Ati Asariah, Esra, ati Meṣullamu,
34 Juda, ati Benjamini, ati Ṣemaiah, ati
Jeremiah.
35 Ati ninu awọn ọmọ awọn alufa mu
fère lọwọ, Sekariah, ọmọ Jonatani, ọmọ
Ṣemaiah, ọmọ Mattaniah, ọmọ Mikaiah,
ọmọ Sakkuri, ọmọ Asafu:
36 Ati awọn arakọnrin rẹ̀, Semaiah, ati
Asaraeli, Milalai, Gilalai, Maai, Netaneeli,
ati Juda, Hanani, pẹlu ohun-èlo orin
Dafidi, enia Ọlọrun, ati Esra akọwe niwaju
wọn.
37 Ati ni ẹnu-bode orisun eyi ni ibi ti o
kọju si i, nwọn ba àtẹgun ilu Dafidi goke
lọ, ni ibi odi ti o goke lọ, ni ikọja ile Dafi-
di, titi de ẹnu-bode omi, niha ila-õrùn.
38 Ati ẹgbẹ keji awọn ti ndupẹ, lọ li odi
keji si wọn, ati emi lẹhin wọn, pẹlu idaji
awọn enia lori odi, lati ikọja ile-iṣọ ileru,
titi de odi gbigboro.
39 Nwọn si rekọja oke ẹnu-bode Efraimu
wá, ati lati oke ẹnu-bode lailai ati li oke
ẹnu-bode ẹja, ati ile-iṣọ Hananieli, ati ile-
iṣọ Mea, titi de ẹnu-bode agutan, nwọn si
duro li ẹnu-bode tubu.
40 Bayi ni awọn ẹgbẹ meji ti ndupẹ ninu
ile Ọlọrun duro, ati emi ati idaji awọn
ijoye pẹlu mi.
41 Ati awọn alufa: Eliakimu, Maaseiah,
Miniamini Mikaiah, Elioenai, Sekariah,
Hananiah mu fère lọwọ;
42 Ati Maaseiah, ati Ṣemaiah, ati Elea-
sari, ati Ussi, ati Jehohanani, ati Malkijah,
ati Elamu, ati Eseri, awọn akọrin kọrin
soke, pẹlu Jesrahiah alabojuto.
43 Li ọjọ na pẹlu nwọn ṣe irubọ nla,
nwọn si yọ̀ nitori Ọlọrun ti mu wọn yọ̀ ayọ̀
nla, aya wọn ati awọn ọmọde yọ̀ pẹlu, tobẹ̃
ti a si gbọ́ ayọ̀ Jerusalemu li okere reré.
44 Li akoko na li a si yàn awọn kan ṣe
olori yara iṣura, fun ọrẹ-ẹbọ, fun akọso,
ati fun idamẹwa, lati ma ko ipin ti a yàn
jọ lati oko ilu wọnni wá, ti ofin fun awọn
alufa ati awọn ọmọ Lefi: nitoriti Juda yọ̀
fun awọn ọmọ Lefi ti o duro.

Digitized by Google

45 Ati awọn akọrin, ati adèna npa ẹṣọ Ọlọrun wọn mọ, ati ẹṣọ iwẹnumọ́, gẹgẹ bi aṣẹ Dafidi ; ati ti Solomoni ọmọ rẹ̀.

46 Nitori li ọjọ Dafidi ati Asafu nigbani awọn olori awọn akọrin wà, ati orin iyìn, ati ọpẹ fun Ọlọrun.

47 Gbogbo Israeli li ọjọ Serubbabeli, ati li ọjọ Nehemiah si fi ipin awọn akọrin, ati ti awọn adèna fun wọn olukuluku ni ipin tirẹ̀ li ojojumọ, nwọn si ya ohun mimọ́ awọn ọmọ Lefi si ọ̀tọ, awọn ọmọ Lefi si yà wọn si ọ̀tọ fun awọn ọmọ Aaroni.

## ORI 13.

LI ọjọ na, a kà ninu iwe Mose li eti gbogbo enia, ati ninu rẹ̀ li a ri pe, ki ara Ammoni ati ara Moabu ki o ma wa sinu ijọ Ọlọrun lailai ;

2 Nitoriti nwọn kò fi onjẹ ati omi kò awọn ọmọ Israeli lọna, ṣugbọn nwọn bẹ Balaamu lọwẹ si wọn, lati fi wọn gegun : ṣugbọn Ọlọrun wa sọ egun na di ibukun.

3 O si ṣe, nigbati nwọn ti gbọ́ ofin na, ni nwọn yà gbogbo awọn ọ̀pọ enia ti o darapọ̀ mọ Israeli kuro.

4 Ati ṣaju eyi, Eliaṣibu alufa, ti o jẹ alabojuto iyẹwu ile Ọlọrun wa jẹ ana Tobiah.

5 O si ti pèse iyẹwu nla kan fun u, nibiti nwọn ima fi ẹbọ ohun jijẹ, turari, ati ohun èlo, ati idamẹwa agbado, ọti-waini titun, ati ororo si nigba atijọ, eyi ti a pa li aṣẹ lati fi fun awọn ọmọ Lefi, ati awọn akọrin, ati awọn adèna : ati ẹbọ ọrẹ awọn alufa.

6 Ṣugbọn ni gbogbo àkoko yi, emi kò si ni Jerusalemu : nitori li ọdun kejilelọgbọn ti Artasasta ọba Babiloni, mo wá si ọdọ ọba, ati li opin ọjọ wọnni, mo gba àye lati ọdọ ọba.

7 Mo si wá si Jerusalemu, mo si mọ̀ buburu ti Eliaṣibu ṣe nitori Tobiah, ni pipèse iyẹwu fun u, ninu àgbala ile Ọlọrun.

8 O si bà mi ninu jẹ gidigidi, nitorina mo da gbogbo ohun-èlo Tobiah jade kuro ninu iyẹwu na.

9 Nigbana ni mo paṣẹ, nwọn si wẹ̀ iyẹwu na mọ : si ibẹ ni mo si tun mu ohun-èlo ile Ọlọrun wá, pẹlu ẹbọ ohun jijẹ ati turari.

10 Mo si mọ̀ pe, a kò ti fi ipin awọn ọmọ Lefi fun wọn ; awọn ọmọ Lefi ati awọn ãkọrin, ti nṣe iṣẹ, si ti salọ olukuluku si oko rẹ̀.

11 Nigbana ni mo si ba awọn ijoye jà, mo si wipe, Ẽṣe ti a fi kọ̀ ile Ọlọrun silẹ ? mo si ko wọn jọ, mo si fi wọn si ipò wọn.

12 Nigbana ni gbogbo Juda mu idamẹwa ọka ati ọti-waini titun ati ororo wá si ile iṣura.

13 Mo si yàn olupamọ si ile iṣura, Ṣelemiah alufa ati Sadoku akọwẹ, ati ninu awọn ọmọ Lefi, Pedaiah : ati lọwọkọwọ wọn ni Hanani ọmọ Sakkuri, ọmọ Mattaniah : nitoriti a kà wọn si olõtọ, oyè wọn si ni lati ma pin fun awọn arakọnrin wọn.

14 Ranti mi, Ọlọrun mi, nitori eyi, ki o má si nu iṣẹ rere ti mo ti ṣe fun ile Ọlọrun mi, nu kuro, ati fun akiyesi rẹ̀.

15 Li ọjọ wọnni ni mo ri awọn kan ti nfunti ni Juda li ọjọ isimi, awọn ti nmu iti ọka wale, ti ndi ẹrù rù kẹtẹkẹtẹ ; ti ọti-waini, pẹlu eso àjara, ati eso ọ̀pọtọ, ati gbogbo oniruru ẹrù ti nwọn nmu wá si Jerusalemu li ọjọ isimi : mo si jẹri gbè wọn li ọjọ ti nwọn ntà ohun jijẹ.

16 Awọn ara Tire ngbe ibẹ pẹlu, ti nwọn mu ẹja, ati oniruru ohun-èlo wá, nwọn si ntà li ọjọ isimi fun awọn ọmọ Juda, ati ni Jerusalemu.

17 Nigbana ni mo ba awọn ijoye Juda jà, mo si wi fun wọn pe, ohun buburu kili ẹnyin nṣe yi, ti ẹ si mba ọjọ isimi jẹ.

18 Bayi ha kọ́ awọn baba nyin ṣe, Ọlọrun kò ha mu ki gbogbo yi wá sori wa, ati sori ilu yi ? ṣugbọn ẹnyin mu ibinu ti o pọ̀ju wá sori Israeli nipa biba ọjọ isimi jẹ.

19 O si ṣe, nigbati ẹnu-bode Jerusalemu bẹ̀rẹ si iṣu okunkun ṣaju ọjọ isimi, mo paṣẹ pe, ki a tì ilẹkun, ki ẹnikẹni má ṣi i titi di ẹ̀hin ọjọ isimi, ninu awọn ọmọkọnrin mi ni mo fi si ẹnu-bode, ki a má ba mu ẹrù wọle wá li ọjọ isimi.

20 Bẽni awọn onisọ̀wo ati awọn ti ntà oniruru nkan sùn lẹhin odi Jerusalemu li ẹrinkan tabi ẹrinmeji.

21 Nigbana ni mo jẹri gbè wọn, mo si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi sùn lẹhin odi, bi ẹnyin ba tun ṣe bẽ, emi o fọwọ bà nyin. Lati àkoko na lọ ni nwọn kò si wá lọjọ isimi mọ.

22 Mo si paṣẹ fun awọn ọmọ Lefi, ki nwọn ya ara wọn si mimọ, ki nwọn si wa ṣọ ẹnu-bode lati pa ọjọ isimi mọ. Ranti mi Ọlọrun mi nitori eyi pẹlu, ki o si da mi si gẹgẹ bi ọ̀pọ ãnu rẹ.

23 Pẹlupẹlu li ọjọ wọnni, mo ri ara Juda ti mba obirin awọn ara Aṣdodi, Ammoni, ati ti Moabu gbe :

24 Awọn ọmọ wọn si nsọ apakan ède Aṣdodi, nwọn kò si le sọ̀rọ li ède awọn ara Juda, ṣugbọn gẹgẹ bi ède olukuluku.

25 Mo si ba wọn jà, mo gàn wọn, mo lù

Digitized by Google

ninu wọn, mo tu irun wọn, mo mu wọn fi
Ọlọrun bura pe, Ẹnyin kì yio fi ọmọbirin
nyin fun ọmọkọnrin nyin tabi fun ara
nyin.
26 Solomoni ọba Israeli kò ha dẹṣẹ nipa
nkan wọnyi? Bẽni li ãrin orilẹ-ède pupọ,
kò si ọba kan bi on ti Ọlọrun rẹ fẹràn;
Ọlọrun si fi jẹ ọba li ori gbogbo Israeli,
bẽni on li awọn àjeji obirin mu ki o ṣẹ̀.
27 Njẹ ki awa ha gbọ́ ti nyin, lati ṣe
gbogbo buburu nla yi, lati ṣẹ̀ si Ọlọrun wa,
ni gbigbe awọn àjeji obirin ni iyawo?
28 Ati ọkan ninu awọn ọmọ Joiada, ọmọ
Eliaṣibu olori alufa, jẹ ana Sanballati, ara
Horoni, nitori na mo le e kuro lọdọ mi.
29 Ranti wọn, Ọlọrun mi, nitoriti nwọn
ti ba oyè alufa jẹ, pẹlu majẹmu oyè-alufa,
ati ti awọn ọmọ Lefi.
30 Bayi ni mo wẹ̀ wọn nù kuro ninu
gbogbo awọn alejo, mo si yan ẹ̀ṣọ awọn
alufa, ati ti awọn ọmọ Lefi, olukuluku ninu
iṣẹ tirẹ̀.
31 Ati fun ẹ̀bun igi li àkoko ti a yàn, ati
fun akọso. Ranti mi, Ọlọrun mi, fun rere.

IWE

# ESTERI.

## ORI 1.

O SI ṣe li ọjọ Ahaswerusi, (eyi ni Aha-
swerusi ti o jọba lati India, ani titi o
fi de Etiopia, lori ẹtadiladoje ìgberiko:)
2 Li ọjọ wọnni, nigbati Ahaswerusi, ọba,
joko lori itẹ ijọba rẹ̀, ti o wà ni Ṣuṣani,
ãfin.
3 Li ọdun kẹta ijọba rẹ̀, o sè àse kan fun
gbogbo awọn ijoye ati awọn iranṣẹ rẹ̀; awọn
balogun Persia ati Media, awon ọlọla, ati
awọn olori ìgberiko wọnni wà niwaju rẹ̀:
4 Nigbati o fi ọrọ̀ ijọba rẹ̀ ti o logo, ati
ọṣọ iyebiye ọlanla rẹ̀ han lọjọ pipọ̀, ani li
ọgọsan ọjọ.
5 Nigbati ọjọ wọnyi si pari, ọba sè àse
kan li ọjọ meje fun gbogbo awọn enia ti a
ri ni Ṣuṣanì ãfin, ati àgba ati ewe ni agbala
ọgba ãfin ọba.
6 Nibiti a gbe ta aṣọ àla daradara, aṣọ
alaro, ati òféfe, ti a fi okùn ọ̀gbọ daradara,
ati elesè aluko dimu mọ oruka fadaka, ati
ọwọ̀n okuta marbili: wura ati fadaka ni
irọgbọku, ti o wà lori ilẹ ti a fi okuta ala-
bastari, marbili, ilẹ̀kẹ daradara, ati okuta
dudu tẹ́.
7 Ninu ago wura li a si nfun wọn mu,
(awọn ohunelo na si yatọ si ara wọn) ati
ọti-waini ọba li ọ̀pọlọpọ gẹgẹ bi ọwọ ọba ti
to.
8 Gẹgẹ bi aṣẹ si ni mimu na; ẹnikẹni
kò fi ipa rọ̀ ni: nitori bẽni ọba ti fi aṣẹ fun
gbogbo awọn olori ile rẹ̀, ki nwọn ki o le
ṣe gẹgẹ bi ifẹ olukuluku.
9 Fasti ayaba sè àse pẹlu fun gbogbo
awọn obirin ni ile ọba ti iṣe ti Ahaswerusi.
10 Li ọjọ keje, nigbati ọti-waini mu inu
ọba dùn, o paṣẹ fun Mehumani, Bista,
Harbona, Bigta ati Abagta, Ṣetari ati
Karkasi, awọn iwẹfa meje ti njiṣẹ niwaju
Ahaswerusi ọba.
11 Lati mu Faṣti, ayaba wá siwaju ọba,
ti on ti ade ọba, lati fi ẹwà rẹ̀ hàn awọn
enia, ati awọn ijoye: nitori arẹwà obirin
ni.
12 Ṣugbọn Faṣti ayaba kọ̀ lati wá nipa
aṣẹ ọba lati ọwọ awọn ìwẹfa rẹ̀: nitorina ni
ọba binu gidigidi, ibinu rẹ̀ si gbiná ninu
rẹ̀.
13 Ọba si bi awọn ọlọgbọ́n, ti nwọn
moye akokò, (nitori bẽni ìwa ọba ri si gbo-
gbo awọn ti o mọ̀ ofin ati idajọ:
14 Awọn ti o sunmọ ọ ni Karṣina, Ṣeta-
ri, Admata, Tarṣiṣi, Meresi, Marsena, ati
Memukani, awọn ijoye Persia ati Media
mejeje, ti nri oju ọba, ti nwọn si joko ni
ipò ikini ni ijọba).
15 Pe, gẹgẹ bi ofin, Kini ki a ṣe si Faṣti
ayaba, nitoriti on kò ṣe bi Ahaswerusi ọba
ti paṣẹ fun u, lati ọwọ awọn ìwẹfa rẹ̀ wá?
16 Memukani si dahùn niwaju ọba ati
awọn ijoye pe, Faṣti ayaba kò ṣẹ̀ si ọba
nikan, ṣugbọn si gbogbo awọn ijoye, ati si

gbogbo awọn enia ti o wà ni ìgberiko Ahaswerusi ọba.
17 Nitori ìwa ayaba yi yio tàn de ọdọ gbogbo awọn obirin, tobẹ̃ ti ọkọ wọn yio di gigàn loju wọn, nigbati a o sọ ọ wi pe, Ahaswerusi ọba paṣẹ pe, ki a mu Faṣti ayaba wá siwaju rẹ̀, sugbọn on kò wá.
18 Awọn ọlọla-obirin Persia ati Media yio si ma wi bakanna li oni yi fun gbogbo awọn ijoye ọba ti nwọn gbọ́ ìwa ti ayaba hù. Bayi ni ẹ̀gan pipọ̀pipọ̀, ati ibinu yio dide.
19 Bi o ba dara loju ọba, ki aṣẹ ọba ki o ti ọdọ rẹ̀ lọ, ki a si kọ ọ pẹlu awọn ofin Persia ati Media, ki a má ṣe le pa a dà, pe, ki Faṣti ki o máṣe wá siwaju Ahaswerusi ọba mọ, ki ọba ki o si fi oyè ayaba rẹ̀ fun ẹgbẹ rẹ̀ ti o san jù u lọ.
20 Ati nigbati a ba si kede aṣẹ ọba ti on o pa yi gbogbo ijọba rẹ̀ ka, (nitori on sa pọ̀) nigbana ni gbogbo awọn obirin yio ma bọ̀wọ fun ọkọ wọn, ati àgba ati ewe.
21 Ọrọ na si dara loju ọba ati awọn ijoye; ọba si ṣe gẹgẹ bi ọ̀rọ Memukani:
22 Nitori on ran ìwe si gbogbo ìgberiko ọba, si olukulùku ìgberiko gẹgẹ bi ikọwe rẹ̀, ati si olukulùku enia gẹgẹ bi èdè rẹ̀, ki olukulùku ọkọnrin ki o le ṣe olori ni ile tirẹ̀, ati ki a le kede rẹ̀ gẹgẹ bi èdè enia rẹ̀.

## ORI 2.

LẸHIN nkan wọnyi, nigbati ibinu Ahaswerusi ọba wa tuka, o ranti Faṣti, ati ohun ti o ti ṣe, ati aṣẹ ti a ti pa nitori rẹ̀.
2 Nigbana ni awọn ọmọ-ọdọ ọba, ti nṣe iranṣẹ fun u, wi pe, jẹ ki a wá awọn wundia ti o li ẹwà fun ọba.
3 Ki ọba ki o si yàn olori ni gbogbo ìgberiko ijọba rẹ̀, ki nwọn ki o le ṣà awọn wundia ti o li ẹwà jọ wá si Ṣuṣani ãfin, si ile awọn obirin, si ọdọ Hegai, ìwẹfa ọba olutọju awọn ọbirin; ki a si fi elo ìwẹnumọ́ wọn fun wọn:
4 Ki wundia na ti o ba wù ọba ki o jẹ ayaba ni ipò Faṣti. Nkan na si dara loju ọba, o si ṣe bẹ̃.
5 Ọkọnrin ara Juda kan wà ni Ṣuṣani ãfin, orukọ ẹniti ijẹ Mordekai, ọmọ Jairi, ọmọ Ṣemei, ọmọ Kisi, ara Benjamini.
6 Ẹniti a ti mu lọ lati Jerusalemu pẹlu ìgbekun ti a kó lọ pẹlu Jekoniah, ọba Juda, ti Nebukadnessari, ọba Babeli ti kó lọ.
7 On li o si tọ́ Hadassa dagba, eyini ni Esteri, ọmọbirin arakọnrin baba rẹ̀: nitori kò ni baba, bẹ̃ni kò si ni iya, wundia na si li ẹwà, o si dara lati wò; ẹniti, nigbati baba ati iya rẹ̀ ti kú tan, Mordekai mu u ṣe ọmọbirin ontikalarẹ̀,
8 O si ṣe, nigbati a gbọ́ ofin ọba, ati aṣẹ rẹ̀, nigbati a si ṣà ọ̀pọlọpọ wundia jọ si Ṣuṣani ãfin, si ọwọ Hegai, a si mu Esteri wá si ile ọba pẹlu si ọwọ Hegai, olutọju awọn obirin.
9 Wundia na si wù u, o si ri ojurere gbà lọdọ rẹ̀; o si yara fi elo ìwẹnumọ́ rẹ̀ fun u, ati ipin onjẹ ti o jẹ tirẹ̀, ati obirin meje ti a yàn fun u lati ile ọba wá: on si ṣi i lọ ati awọn wundia rẹ̀ si ibi ti o dara jù ni ile awọn obirin.
10 Esteri kò ti ifi awọn enia rẹ̀, tabi awọn ibatan rẹ̀ hàn; nitori Mordekai paṣẹ fun u ki o máṣe fi hàn.
11 Mordekai a si ma rìn lojojumọ niwaju àgbala ile awọn obirin, lati mọ̀ alafia Esteri, ati bi yio ti ri fun u.
12 Njẹ nigbati o kan olukuluku wundia lati wọ̀ ile tọ̀ Ahaswerusi ọba lọ, lẹhin igbati on ba ti gbe oṣù mejila, gẹgẹ bi iṣe awọn obirin, (nitori bayi ni ọjọ ìwẹnumọ́ wọn pari, oṣù mẹfa ni nwọn fi ikùn òroro ojiá, ati oṣù mẹfa òroro olõrùn didùn, ati pẹlu ohunelo ìwẹnumọ́ awọn obirin):
13 Bayi ni wundia na iwá si ọdọ ọba; ohunkohun ti o ba bère li a si ifi fun u, lati ba a lọ, lati ile awọn obirin lọ si ile ọba.
14 Li aṣãlẹ on a lọ, ni õrọ ijọ keji on a si pada si ile keji ti awọn obirin, si ọwọ Ṣaaṣgasi, ìwẹfa ọba, ti nṣe olutọju awọn obirin, on kò si gbọdọ wọle tọ̀ ọba wá mọ, bikoṣepe inu ọba ba dùn si i, ti a ba si pè e li orukọ.
15 Njẹ nigbati o kan Esteri, ọmọ Abihaili, arakọnrin Mordekai, ẹniti o mu u ṣe ọmọ ara rẹ̀, lati wọle tọ̀ ọba lọ, on kò bère ohunkohun bikoṣe ohun ti Hegai, ìwẹfa ọba, olutọju awọn obirin paṣẹ. Esteri si ri ojurere lọdọ gbogbo ẹniti nwò o.
16 Bẹ̃li a mu Esteri wá si ọdọ Ahaswerusi ọba, sinu ile ọba, li oṣù kẹwa, ti iṣe oṣù Tibeti, li ọdun keje ijọba rẹ̀.
17 Ọba si fẹràn Esteri jù gbogbo awọn obirin lọ, on si ri ore-ọfẹ ati oju-rere lọdọ rẹ̀ jù gbogbo awọn wundia na lọ; tobẹ̃ ti o fi gbe ade ọba kà a li ori, o si fi i ṣe ayaba ni ipò Faṣti.
18 Ọba si sè àse nla kan fun gbogbo awọn olori rẹ̀, ati awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀, ani àse ti Esteri; o si fi isimi fun awọn ìgberiko rẹ̀, o si ṣe itọrẹ gẹgẹ bi ọwọ ọba ti to.
19 Nigbati a si kó awọn wundia na jọ li ẹrinkeji, nigbana ni Mordekai joko li ẹnu ọ̀na ile ọba.

Digitized by Google

20 Esteri kò ti ifi awọn ibatan, tabi awọn enia rẹ̀ hàn titi disisiyi bi Mordekai ti paṣẹ fun u: nitori Esteri npa ofin Mordekai mọ́, bi igba ti o wà li abẹ itọ́ rẹ̀.

21 Li ọjọ wọnni, nigbati Mordekai njoko li ẹnu ọ̀na ile ọba, meji ninu awọn iwẹfa ọba, Bigtani ati Tereṣi, ninu awọn ti nṣọ iloro, nwọn binu, nwọn si nwá ọ̀na lati gbe ọwọ le Ahaswerusi ọba.

22 Nkan na si di mimọ̀ fun Mordekai, o si sọ fun Esteri ayaba; Esteri si fi ọ̀ran na hàn ọba li orukọ Mordekai.

23 Nigbati nwọn si wadi ọ̀ran na, nwọn ri idi rẹ̀; nitorina a so awọn mejeji rọ̀ sori igi; a si kọ ọ sinu iwe-iranti niwaju ọba.

## ORI 3.

LẸHIN nkan wọnyi ni Ahaswerusi ọba gbe Hamani, ọmọ Medata, ara Agagi ga, o si gbe e lekè, o si fi ijoko rẹ̀ lekè gbogbo awọn ijoye ti o wà pẹlu rẹ̀.

2 Gbogbo awọn iranṣẹ ọba, ti nwọn wà li ẹnu-ọ̀na ọba, kunlẹ nwọn si wolẹ fun Hamani: nitori ọba ti paṣẹ bẽ nitori rẹ̀. Ṣugbọn Mordekai kò kunlẹ, bẽni kò si wolẹ fun u.

3 Nigbana ni awọn iranṣẹ ọba, ti nwọn wà li ẹnu ọ̀na ọba, wi fun Mordekai pe, ẽṣe ti iwọ fi nré ofin ọba kọja?

4 O si ṣe, nigbati nwọn wi fun u lojojumọ, ti on kò si gbọ́ ti wọn, nwọn sọ fun Hamani, lati wò bi ọ̀ran Mordekai yio ti le ri: nitori on ti wi fun wọn pe, enia Juda ni on.

5 Nigbati Hamani si ri pe, Mordekai kò kunlẹ, bẽni kò wolẹ fun on, nigbana ni Hamani kún fun ibinu.

6 O si jẹ abùkun loju rẹ̀ lati gbe ọwọ le Mordekai nikan; nitori nwọn ti fi awọn enia Mordekai hàn a: nitorina gbogbo awọn Ju ti o wà ni gbogbo ijọba Ahaswerusi, ni Hamani wá ọ̀na lati parun, ani awọn enia Mordekai.

7 Li oṣù kini, eyinì ni oṣù Nisani, li ọdun kejila ijọba Ahaswerusi, nwọn da puri, eyinì ni, ìbo, niwaju Hamani, lati ọjọ de ọjọ, ati lati oṣù de oṣù lọ ide oṣù kejila, eyinì ni oṣù Adari.

8 Hamani si sọ fun Ahaswerusi ọba pe, awọn enia kan fọn kakiri, nwọn si tuka lãrin awọn enia ni gbogbo ìgberiko ijọba rẹ, ofin wọn si yatọ si ti gbogbo enia; bẽni nwọn kò si pa ofin ọba mọ́; nitorina kò yẹ fun ọba lati da wọn si.

9 Bi o ba wù ọba, jẹ ki a kọwe rẹ̀ pe, ki a run wọn: emi o si wọ́n ẹgbãrun talenti fadaka fun awọn ti a fi iṣẹ na rán, ki nwọn ki o le mu u wá sinu ile iṣura ọba.

10 Ọba si bọ́ oruka rẹ̀ kuro li ọwọ rẹ̀, o si fi fun Hamani, ọmọ Medata, ara Agagi, ọta awọn Ju.

11 Ọba si wi fun Hamani pe, a fi fadaka na bún ọ, ati awọn enia na pẹlu, lati fi wọn ṣe bi o ti dara loju rẹ̀.

12 Nigbana li a pè awọn akọwe ọba ni ọjọ kẹtala, oṣù kini, a si kọwe gẹgẹ bi gbogbo ohun ti Hamani ti pa li aṣẹ fun awọn bãlẹ ọba, ati fun awọn onidajọ ti o njẹ olori gbogbo ìgberiko, ati fun awọn olori olukuluku enia ìgberiko gbogbo, gẹgẹ bi ikọwe rẹ̀, ati fun olukuluku enià gẹgẹ bi ède rẹ̀, li orukọ Ahaswerusi ọba li a kọ ọ, a si fi oruka ọ̀ba ṣe edidi rẹ̀.

13 A si fi iwe na rán awọn ọ̀jiṣẹ si gbogbo ìgberiko ọba, lati parun, lati pa, ati lati mu ki gbogbo enia Juda, ati ọ̀dọ́ ati arugbo, awọn ọmọde, ati awọn obirin ki o ṣegbe ni ọjọ kan, ani li ọjọ kẹtala, oṣù kejila, ti iṣe oṣù Adari, ati lati kó ohun ini wọn fun ijẹ.

14 Ọran iwe na ni lati paṣẹ ni gbogbo igberiko, lati kede rẹ̀ fun gbogbo enia, ki nwọn ki o le mura de ọjọ na.

15 Awọn ojiṣẹ na jade lọ, nwọn si yara, nitori aṣẹ ọba ni, a si pa aṣẹ na ni Ṣuṣani ãfin. Ati ọba ati Hamani joko lati mu ọti; ṣugbọn ilu Ṣuṣani dãmu.

## ORI 4.

NIGBATI Mordekai mọ̀ gbogbo ohun ti a ṣe, Mordekai fa aṣọ rẹ̀ ya, o si fi aṣọ-ọ̀fọ on ẽru bò ara, o si jade lọ si ãrin ilu na, o si sọkun kikan ati kikoro.

2 O tilẹ wá siwaju ẹnu-ọna ile ọba: nitori kò si ẹnikan ti o fi aṣọ-ọfọ si ara ti o gbọdọ wọ̀ ẹnu-ọ̀na ile ọba.

3 Ati ni gbogbo ìgberiko, nibiti ofin ọba, ati aṣẹ rẹ̀ ba de, ọ̀fọ nla ba gbogbo awọn Ju; ati ãwẹ̀, ati ẹkún, ati ipọhùnrere; ọ̀pọlọpọ li o si dubulẹ ninu aṣọ-ọ̀fọ, ati ninu ẽru.

4 Bẽli awọn iranṣẹbirin Esteri ati awọn ìwẹfa rẹ̀ wá, nwọn si sọ fun u. Nigbana ni inu ayaba bajẹ gidigidi; o si fi aṣọ ranṣẹ lati fi wọ̀ Mordekai, ati lati mu aṣọ-ọ̀fọ rẹ̀ kuro lara rẹ̀, ṣugbọn on kò gbà a.

5 Nigbana ni Esteri pè Hataki, ọkan ninu awọn ìwẹfa ọba, ẹniti o ti yàn lati duro niwaju rẹ̀, o si rán a si Mordekai lati mọ̀ ohun ti o ṣe, ati nitori kini?

6 Bẽni Hataki jade tọ̀ Mordekai lọ si ita ilu niwaju ẹnu-ọ̀na ile ọba.

Digitized by Google

7 Mordekai si sọ ohun gbogbo ti o ri to
fun u, ati ti iye owo fadaka ti Hamani ti
ṣe ileri lati san si ile iṣura ọba, nitori awọn
Ju, lati pa wọn run.
8 Ati pẹlu, o fi iwe aṣẹ na pãpã, ti a pa
ni Ṣuṣani lati pa awọn Ju run, le e lọwọ,
lati fi hàn Esteri, ati lati sọ fun u, ati lati
paṣẹ fun u ki on ki o wọle tọ̀ ọba lọ, lati
bẹ̀bẹ lọwọ rẹ̀, ati lati bẹ̀bẹ niwaju rẹ̀, nitori
awọn enia rẹ̀.
9 Hataki si wá o si sọ gbogbo ọ̀rọ Mor-
dekai fun Esteri.
10 Esteri si tun sọ fun Hataki, o si rán
a si Mordekai.
11 Pe, gbogbo awọn iranṣẹ ọba, ati
awọn enia ìgberiko ọba li o mọ̀ pe, ẹnikẹni
ibaṣe ọkọnrin tabi obirin, ti o ba tọ̀ ọba wá
sinu àgbala ti inu, ti a kò ba pè, ofin rẹ̀
kan ni, ki a pa a, bikoṣe iru ẹniti ọba ba
nà ọpá alade wura si, ki on ki o le yè:
ṣugbọn a kò ti ipè mi lati wọ̀ ile tọ̀ ọba
lọ lati ìwọn ọgbọn ọjọ yi wá.
12 Nwọn si sọ ọ̀rọ Esteri fun Mordekai.
13 Nigbana ni Mordekai sọ ki a da
Esteri lohùn pe, Máṣe rò ninu ara rẹ pe,
iwọ o là ninu ile ọba jù gbogbo awọn Ju lọ.
14 Nitori bi iwọ ba pa ẹnu rẹ mọ́ pata-
pata li akokò yi, nigbana ni iranlọwọ ati
igbala awọn Ju yio dide lati ibomiran wá;
ṣugbọn iwọ ati ile baba rẹ li ao parun: tali
o si mọ̀ bi nitori iru akokò bayi ni iwọ ṣe
de ijọba?
15 Nigbana ni Esteri rán wọn lọ ifi èsi
yi fun Mordekai pe,
16 Lọ, pè awọn Ju ti a le ri ni Ṣuṣani
jọ, ki ẹnyin si ma gbãwẹ fun mi, ki ẹnyin
ki o máṣe jẹun, bẽni ki ẹnyin ki o máṣe mu
ni ijọ mẹta t'ọsan t'oru: emi pẹlu ati awọn
iranṣẹbirin mi yio gbãwẹ bẽ gẹgẹ; bẽli emi
o si wọ̀ ile tọ̀ ọba lọ, ti o lòdi si ofin; bi
mo ba ṣègbe, mo ṣègbe.
17 Bẽni Mordekai ba ọ̀na rẹ̀ lọ, o si ṣe
gẹgẹ bi gbogbo eyiti Esteri ti paṣẹ fun u.

## ORI 5.

O SI ṣe li ọjọ kẹta, ni Esteri wọ̀ aṣọ ayaba
rẹ̀, o si duro ni àgbala ile ọba ti o wà
ninu, lọgangan ile ọba: ọba si joko lori itẹ
ijọba rẹ̀ ni ile ọba, ti o kọjusi ẹnu-ọ̀na ile
na.
2 O si ṣe nigbati ọba ri ti Esteri ayaba
duro ni àgbala, on si ri ore-ọfẹ loju rẹ̀: ọba
si nà ọpá alade wura ti o wà lọwọ rẹ̀ si
Esteri. Esteri si sunmọ ọ, o si fi ọwọ kàn
ori ọpá alade na.
3 Nigbana ni ọba bi i pe, Kini iwọ nfẹ́,
Esteri ayaba? ati kini ẹ̀bẹ rẹ̀? ani de idajì
ijọba li a o si fi fun ọ.
4 Esteri si dahùn pe, bi o ba dara loju
ọba, jẹ ki ọba ati Hamani ki o wá loni
si àse mi, ti mo ti mura silẹ fun u.
5 Nigbana ni ọba wi pe, ẹ mu ki Ha-
mani ki o yara, ki on ki o le ṣe bi Esteri
ti wi. Bẽni ọba ati Hamani wá si àse na
ti Esteri ti sè silẹ.
6 Ọba si wi fun Esteri nibiti nwọn gbe
nmu ọti-waini pe, kini ibere rẹ? a o si fi
fun ọ: ki si ni ẹ̀bẹ rẹ? ani de idajì ijọba,
a o si ṣe e.
7 Nigbana ni Esteri dahùn, o si wi pe,
ẹ̀bẹ mi ati ibère mi ni pe,
8 Bi mo ba ri ore-ọfẹ loju ọba, bi o ba
si wù ọba lati fi ohun ti emi ntọrọ fun mi,
ati lati ṣe ohun ti emi mbère fun mi, jẹ
ki ọba ati Hamani ki o wá si àse ti emi
o si tun sè fun wọn, emi o si ṣe li ọla bi
ọba ti wi.
9 Nigbana ni Hamani jade lọ li ọjọ na
tayọ̀tayọ̀, ati pẹlu inu didùn: ṣugbọn ni-
gbati Hamani ri Mordekai li ẹnu-ọ̀na ile
ọba pe, kò dide duro, bẽni kò pa ara rẹ̀
dà fun on, Hamani kún fun ibinu si
Mordekai.
10 Ṣugbọn Hamani kó ara rẹ̀ ni ijanu:
nigbati o si de ile, o ranṣẹ lọ ipè awọn ọrẹ
rẹ̀, ati Sereṣi aya rẹ̀.
11 Hamani si ròhin ogo ọrọ̀ rẹ̀, ati ọ̀pọ-
lọpọ awọn ọmọ rẹ̀, ati ninu ohun gbogbo
ti ọba fi gbe e ga, ati bi o ti gbe on ga
jù awọn ijoye, ati awọn ọmọ-ọdọ ọba lọ.
12 Hamani si wi pẹlu pe, ani Esteri
ayaba kò mu ki ẹnikẹni ki o ba ọba wá
si ibi àse ti o ti sè bikoṣe emi nikan; li
ọla ẹ̀wẹ li a si tun pè mi pẹlu ọba lati wá
si ọdọ rẹ̀,
13 Ṣugbọn gbogbo wọnyi kò di nkankan
fun mi, niwọ̀n igbati mo ba ri Mordekai,
ara Juda nì, ti o joko li ẹnu-ọ̀na ile ọba.
14 Nigbana ni Sereṣi aya rẹ̀, ati gbogbo
awọn ọrẹ rẹ̀ wi fun u pe, Jẹ ki a rì igi
kan, ki o ga ni ãdọta igbọnwọ, ati li ọla
ni ki o ba ọba sọ ọ ki a so Mordekai rọ̀
nibẹ: iwọ o si fi ayọ̀ ba ọba lọ si ibi àse.
Nkan yi dùn mọ Hamani, o si rì igi na.

## ORI 6.

LI oru na ọba kò le sùn, o si paṣẹ pe, ki
a mu iwe-iranti, ani irohin awọn ọjọ
wá, a si kà wọn niwaju ọba.
2 A si ri pe, ati kọ ọ pe, Mordekai ti
sọ ti Bigtani, ati Tereṣi, awọn ìwẹfa ọba

Digitized by Google

meji, olusọ iloro, awọn ẹniti nwá ọ̀na lati
gbe ọwọ le Ahaswerusi ọba.
3 Ọba si wi pe, Iyìn ati olá wo li a
fi fun Mordekai nitori eyi? Nigbana ni
awọn ọmọ-ọdọ ọba ti nṣe iranṣẹ fun u wi
pe, a kò ṣe nkankan fun u.
4 Ọba si wi pe, Tani mbẹ ni àgbala?
Hamani si ti de àgbala akọkàn ile ọba,
lati ba ọba sọ ọ lati so Mordekai rọ̀ sori
igi giga ti o ti rì fun u.
5 Awọn ọmọ-ọdọ ọba si wi fun u pe,
Sa wò o, Hamani duro ni agbala, Ọba si
wi pe, jẹ ki o wọle.
6 Bẹ̃ni Hamani si wọle wá, Ọba si wi
fun u pe, kini a o ṣe fun ọkọnrin na
ẹniti inu ọba dùn si lati bù ọlá fun? Njẹ
Hamani rò ninu ọkàn ara rẹ̀ pe, Tani inu
ọba le dùn si lati bù ọlá fun jù emi tika-
lami lọ?
7 Hamani si da ọba lohùn pe, Ọkọnrin
na ẹniti inu ọba dùn si lati bù ọlá fun.
8 Jẹ ki a mu aṣọ ọba ti ọba ima wọ̀,
ati ẹṣin ti ọba ima gùn, ati ade ọba ti ima
gbe kà ori rẹ̀ wá;
9 Ki a si fi ẹ̀wu ati ẹṣin yi le ọwọ ọkan
ninu awọn ijoye ọba ti o lọlajùlọ, ki nwọn
fi ṣe ọṣọ fun ọkọnrin na, ẹniti inu ọba dùn
si lati bù ọlá fun, ki o si mu u gẹṣin là
igboro ilu, ki o si ma kigbe niwaju rẹ̀ pe,
Bayi li a o ṣe fun ọkọnrin na, ẹniti inu
ọba dùn si lati bù ọlá fun.
10 Nigbana ni ọba wi fun Hamani pe,
yara kánkán, mu ẹ̀wu ati ẹṣin na, bi iwọ
ti wi, ki o si ṣe bẹ̃ gẹgẹ fun Mordekai, ara
Juda nì, ti njoko li ẹnu ọ̀na ile ọba:
ohunkohun kò gbọdọ yẹ̀ ninu ohun ti iwọ
ti sọ.
11 Nigbana ni Hamani mu aṣọ ati ẹṣin
na, o si ṣe Mordekai li ọṣọ́, o si mu u là
igboro ilu lori ẹṣin, o si kigbe niwaju rẹ̀
pe, Bayi li a o ṣe fun ọkọnrin na ẹniti inu
ọba dùn si lati bù ọlá fun.
12 Mordekai si tun pada wá si ẹnu-ọ̀na
ile ọba, ṣugbọn Hamani yara lọ si ile rẹ̀
ti on ti ibinujẹ, o si bò ori rẹ̀.
13 Hamani si sọ gbogbo ohun ti o ba
a, fun Sereṣi obirin rẹ̀, ati gbogbo awọn
ọrẹ rẹ̀. Nigbana ni awọn enia rẹ̀, amoye,
ati Sereṣi obirin rẹ̀, wi fun u pe, Bi
Mordekai ba jẹ iru-ọmọ awọn Ju, niwaju
ẹniti iwọ ti bẹ̀rẹ si iṣubu na, iwọ kì yio
le bori rẹ̀, ṣugbọn iwọ o ṣubu niwaju rẹ̀
dandan.
14 Bi nwọn si ti mba a sọ̀rọ lọwọ, awọn
ìwẹfa ọba de, lati wá mu Hamani yára wá
si ibi àse ti Esteri sè.

## ORI 7.

BẸ̃NI ọba ati Hamani wá iba Esteri
ayaba jẹ àse.
2 Ọba si tun wi fun Esteri ni ijọ keji ni
ibi àse ti nwọn nmu ọti-waini pe, kini ẹbẹ
rẹ, Esteri ayaba? a o si fi fun ọ: ki si ni
ibère rẹ? a o si ṣe e, ani lọ ide idaji ijọba.
3 Nigbana ni Esteri ayaba dahùn wi pe,
bi mo ba ri ore-ọfẹ loju rẹ ọba, bi o ba si
wù ọba, mo bẹbẹ ki a fi ẹmi mi bùn mi
nipa ẹbẹ mi, ati awọn enia mi nipa ibère
mi.
4 Nitori a ti tà wa, emi ati awọn enia
mi, lati run wa, lati pa wa, ki a le parun.
Ṣugbọn bi o ṣe pe, a ti tà wa fun ẹrùkọnrin,
ati ẹrúbirin ni, emi iba pa ẹnu mi mọ́, bi
o tilẹ jẹ pe ọta na kò le di ofò ọba.
5 Nigbana ni Ahaswerusi ọba dahùn,
o si wi fun Esteri ayaba pe, Tali oluwa
rẹ̀ na, nibo li o si wà, ti o jẹ gbe e le ọkàn
rẹ̀ lati ṣe bẹ̃?
6 Esteri si wi pe, ọlọtẹ enia ani ọta na
ni Hamani, ẹnibuburu yi. Nigbana ni ẹ̀ru
ba Hamani niwaju ọba ati ayaba.
7 Ọba si dide ni ibinu rẹ̀ kuro ni ibi
àse ti nwọn nmu ọti-waini, o bọ́ si àgbala
ãfin: Hamani si dide duro lati tọrọ ẹmi
rẹ̀ lọwọ Esteri ayaba; nitori o ti ri pe ọba
ti pinnu ibi si on.
8 Nigbana ni ọba pẹhinda lati inu
àgbala ãfin sinu ibiti nwọn nmu ọti-waini,
Hamani si ṣubu le ibi ìrọgbọkú lori eyi
ti Esteri joko; nigbana ni ọba wi pe, yio
ha tẹ́ ayaba lọdọ mi ninu ile bi? Bi ọ̀rọ
na ti ti ẹnu ọba jade, nwọn bò oju Hamani.
9 Harbona ọkan ninu awọn ìwẹfa si wi
niwaju ọba pe, Sa wò o, igi ti o ga ni
ãdọta igbọnwọ ti Hamani ti rì nitori Mor-
dekai ti o ti sọ ọ̀rọ rere fun ọba, o wà
li oró ni ile Hamani. Ọba si wi pe, Ẹ
so o rọ̀ lori rẹ̀.
10 Bẹ̃ni nwọn so Hamani rọ̀ sori igi ti
o ti rì fun Mordekai; ibinu ọba si rọ̀.

## ORI 8.

NI ijọ na ni Ahaswerusi ọba fi ile Hamani
ọta awọn Ju, jìn Esteri, ayaba; Mor-
dekai si wá siwaju ọba; nitori Esteri ti
sọ bi o ti ri si on.
2 Ọba si bọ́ oruka rẹ̀, ti o ti gbà lọwọ
Hamani, o si fi i fun Mordekai. Esteri
si fi Mordekai ṣe olori ile Hamani.
3 Esteri si tun sọ niwaju ọba, o wolẹ
lẹba ẹsẹ̀ rẹ̀, o si fi omijé bẹ̀ ẹ pe, ki o mu

Digitized by Google

buburu Hamani, ara Agagi kuro, ati ete
ti o ti pa si awọn Ju.
4 Nigbana ni ọba nà ọpá-alade wura si
Esteri. Bẽni Esteri dide, o si duro niwaju
ọba.
5 O si wi pe, bi o ba wù ọba, bi mo
ba si ri ore-ọfẹ loju rẹ̀, ti nkan na ba si
tọ̀ loju ọba, bi mo ba si wù ọba, jẹ ki
a kọwe lati yí iwe ete Hamani, ọmọ Me-
data, ara Agagi nì pada, ti o ti kọ lati
pa awọn Ju run, ti o wà ni gbogbo ìgberiko
ọba.
6 Nitori pe, emi ti ṣe le ri ibi ti yio
wá ba awọn enia mi? tabi emi ti ṣe le ri
iparun awọn ibatan mi?
7 Nigbana ni Ahaswerusi ọba wi fun
Esteri ayaba, ati fun Mordekai ara Juda
na pe, Sa wò o, emi ti fi ile Hamani fun
Esteri; on ni nwọn si ti so rọ̀ lori igi,
nitoripe o ti gbe ọwọ le awọn Ju.
8 Ẹnyin kọwe ẹ̀wẹ li orukọ ọba, nitori
awọn Ju bi ẹnyin ti fẹ, ki ẹ si fi oruka
ọba ṣe edidi rẹ̀: nitori iwe ti a ba fi orukọ
ọba kọ, ti a ba si fi òruka ọba ṣe edidi,
ẹnikan kò le yi i pada.
9 Nigbana li a si pè awọn akọwe ọba
li akokò na ni oṣù kẹta, ẹyinì ni oṣù
Sifani, li ọjọ kẹtalelogun rẹ̀; a si kọ ọ
gẹgẹ bi Mordekai ti paṣẹ si awọn Ju, ati
si awọn bãlẹ, ati awọn onidajọ, ati olori
awọn ìgberiko metadilãdoje, si olukulùku
ìgberiko gẹgẹ bi ikọwe rẹ̀, ati si olukulùku
enia gẹgẹ bi ède wọn ati si awọn Ju gẹgẹ
bi ikọwe wọn, ati gẹgẹ bi ède wọn.
10 Orukọ Ahaswerusi ọba li a fi kọ ọ,
a si fi oruka ọba sẹ edidi rẹ̀; o si fi iwe
wọnni rán awọn ojiṣẹ lori ẹṣin, ti o gùn
ẹṣin yiyara, ani ibãka, ọmọ awọn abo
ẹṣin.
11 Ninu eyiti ọba fi aṣẹ fun gbogbo awọn
Ju, ti o wà ni ilu gbogbo, lati kó ara wọn
jọ, ati lati duro gbà ẹmi ara wọn là, lati
parun, lati pa, ati lati mu ki gbogbo agba-
ra awọn enia, ati ìgberiko na, ti o ba fẹ
kọlu wọn, pẹlu awọn ọmọ wẹwẹ ati awọn
obirin ki o ṣegbe; ki nwọn ki o si kó ìni
wọn fun ara wọn,
12 Li ọjọ kanṣoṣo ni gbogbo ìgberiko
Ahaswerusi ọba, li ọjọ kẹtala, oṣù kejila ti
iṣe oṣù Adari.
13 Ọran inu iwe na ni lati paṣẹ ni gbo-
gbo ìgberiko lati kede rẹ̀ fun gbogbo enia,
ki awọn Ju ki o le mura de ọjọ na, lati
gbẹsan ara wọn lara awọn ọta wọn.
14 Bẽni awọn ojiṣẹ ti nwọn gun ẹṣin
yiyara ati ibãka jade lọ, nitori aṣẹ ọba,
nwọn yara, nwọn sare. A si pa aṣẹ yi ni
Ṣuṣani ãfin.
15 Mordekai si jade kuro niwaju ọba,
ninu aṣọ ọba, alaro ati funfun, ati ade wura
nla, ati ẹ̀wu okùn ọ̀gbọ kikuná, ati elese
aluko; ayọ̀ ati inu didùn si wà ni ilu
Ṣuṣani.
16 Awọn Ju, si ni imọlẹ, ati inu didùn,
ati ayọ̀, ati ọlá.
17 Ati ni olukulùku ìgberiko, ati ni
olukuluku ilu nibikibi ti ofin ọba, ati aṣẹ
rẹ̀ ba de, awọn Ju ni ayọ̀ ati inudidùn, àse,
ati ọjọ rere. Ọ̀pọlọpọ awọn enia ilẹ na si
di enia Juda; nitori ẹ̀ru awọn Ju ba wọn.

## ORI 9.

NJẸ li oṣù kejila, eyini ni oṣù Adari, li
ọjọ kẹtala rẹ̀, ti ofin ọba ati aṣẹ rẹ̀
sunmọle lati mu u ṣẹ, li ọjọ ti awọn ọta awọn
Ju ti rò pe, awọn o bori wọn, (bi o tilẹ ti
jẹ pe, ati yi i pada pe, ki awọn Ju ki o
bori awọn ti o korira wọn;)
2 Awọn Ju kó ara wọn jọ ninu ilu wọn
ninu gbogbo ìgberiko Ahaswerusi ọba, lati
gbe ọwọ le iru awọn ti o nwá ifarapa wọn:
ẹnikẹni kò si le kò wọn loju; nitori ẹ̀ru
wọn bà gbogbo enia.
3 Gbogbo awọn olori ìgberiko, ati awọn
bãlẹ, ati awọn onidajọ, ati awọn ti nṣe iṣẹ
ọba, ràn awọn Ju lọwọ, nitori ẹ̀ru Mordekai
bà wọn.
4 Nitori Mordekai tobi ni ile ọba, okiki
rẹ̀ si kàn ja gbogbo ìgberiko: nitori ọkọn-
rin yi Mordekai ntobi siwaju ati siwaju.
5 Bayi ni awọn Ju fi idà ṣá gbogbo awọn
ọta wọn pa, ni pipa ati piparun, nwọn si ṣe
awọn ọta ti o korira wọn bi nwọn ti fẹ.
6 Ati ni Ṣuṣani ãfin awọn Ju pa ẽdẹgbẹ-
ta ọkọnrin run.
7 Ati Farṣandata, ati Dalfoni, ati Aspa-
ta,
8 Ati Porata, ati Adalia, ati Aridata,
9 Ati Farmaṣta, ati Arisai, ati Aridai
ati Fajisata,
10 Awọn ọmọ Hamani, ọmọ Medata,
mẹwẹwa, ọta awọn Ju ni nwọn pa; ṣugbọn
nwọn kò fi ọwọ kàn nkan wọn.
11 Li ọjọ na a mu iye awọn ti a pa ni
Ṣuṣani ãfin wá siwaju ọba.
12 Ọba si wi fun Esteri ayaba pe, Awọn
Ju pa, nwọn si ti pa ẽdẹgbẹta enia run ni
Ṣuṣani ãfin, ati awọn ọmọ Hamani mẹwẹ-
wa: kini nwọn ha ṣe ni gbogbo ìgberiko
ọba iyokù? nisisiyi kini ẹbẹ rẹ? a o si fi
fun ọ: tabi kini iwọ o si tun bère si i? a o
si ṣe e.

Digitized by Google

Nigbana ni Esteri wipe, Bi o ba wù
ję ki a fi aşę fun awọn Ju ti o wà ni
ıi ki nwọn ki o şe li ọlá pęlu gęgę bi
i oni, ki a si so awọn ọmọ Hamani
ęwa rọ̀ lori igi.
Ọba si paşę pe, ki a şe bę̃; a si pa aşę
i Şuşani; a si so awọn ọmọ Hamani
ęwa rọ̀.
Nitorina awọn Ju ti o wà ni Şuşani
ra wọn jọ li ọjọ kęrinla oşù Adari pęlu,
ı si pa ọ̃durun ọkọnrin ni Şuşani:
ọn nwọn kò fi ọwọ kàn nkan wọn.
Şugbọn awọn Ju miran, ti o wà ni
riko ọba, kó ara wọn jọ, nwọn dide
lati gbà ęmi ara wọn là, nwọn si
kuro lọwọ awọn ọta wọn, nwọn si pa
-mętadilogoji enia o le ęgbęrun ninu
ı ọta wọn, şugbọn nwọn kò fi ọwọ kàn
ı wọn.
' Li ọjọ kętala oşù Adari, ati li ọjọ
nla rę̀ ni nwọn simi, nwọn si şe e li ọjọ
ıti ayọ̀.
3 Şugbọn awọn Ju ti mbę ni Şuşani kó
wọn jọ li ọjọ kętala rę̀, ati li ọjọ kęrinla
ati li ọjọ kę̃dogun rę̀ nwọn simi, nwọn
e li ọjọ àse ati inu didùn.
9 Nitorina awọn Ju ti o wà ni iletò
ıni, ti nwọn ngbe ilu ti kò li odi, nwọn
jọ kęrinla oşù Adari li ọjọ inu-didùn,
àse, ati ọjọ rere, ati ọjọ ti olukulùku
ipin onję ranşę si ęnikeji rę̀.
0 Mordekai si kọwe nkan wọnyi, o si fi
ranşę si gbogbo awọn Ju ti o wà ni gbo-
ìgberiko Ahaswerusi ọba, si awọn ti o
mọ etile, ati awọn ti o jina.
:1 Lati fi eyi lelę larin wọn, ki nwọn ki
ma pa ọjọ kęrinla oşù Adari, ati ọjọ
logun rę̀ mọ́ li ọdọdun.
:2 Bi ọjọ ninu eyiti awọn Ju simi kuro
u awọn ọta wọn, ati oşù ti a sọ ibanuję
n di ayọ̀, ati ọjọ ọ̀fọ di ọjọ rere; ki nwọn
o le sọ wọn di ọjọ àse, ati ayọ̀, ati ọjọ ti
kuluku nfi ipin onję ranşę si ęnikeji rę̀,
ębun fun awọn talaka.
23 Awọn Ju si gbà lati şe bi nwọn ti
ę si işe, ati bi Mordekai si ti kọwe si
n.
24 Pe, Hamani ọmọ Medata, ara Agagi
ọta gbogbo awọn Ju ti gbiro lati pa
ọn Ju run, o si ti da Puri, eyinì ni ibo,
i pa wọn, ati lati run wọn;

25 Şugbọn nigbati Esteri tọ̀ ọba wá, o fi
iwe paşę pe, ki ete buburu ti a ti pa si awọn
Ju ki o le pada si ori on tikalarę̀, ati ki a
so ati on ati awọn ọmọ rę̀ rọ̀ sori igi.
26 Nitorina ni nwọn şe npè ọjọ wọnni ni
Purimu bi orukọ Puri. Nitorina gęgę bi
gbogbo ọ̀rọ inu iwe yi, ati nitori gbogbo
eyi ti oju wọn ti ri nitori ọ̀ran yi, ati eyiti
o ti ba wọn,
27 Awọn Ju lanà rę̀, nwọn si gbà a kanri
wọn, ati fun iru-ọmọ wọn, ati fun gbogbo
awọn ti o dà ara wọn pọ̀ mọ wọn, pe ki o
máşe yę̀, ki nwọn ki o ma pa ọjọ mejeji
wọnyi mọ́ gęgę bi ikọwe wọn, ati gęgę bi
akokò wọn ti a yàn lọdọdun.
28 Ati pe, ki nwọn ma ranti ọjọ wọnyi,
ki nwọn si ma kiyesi i ni irandiran wọn
gbogbo; olukuluku idile, olukuluku ìgbe-
riko, ati olukuluku ilu; ati pe, ki Purimu
wọnyi ki o máşe yę̀ larin awọn Ju, tabi ki
iranti wọn ki o máşe parun ninu iru-ọmọ
wọn.
29 Nigbana ni Esteri ayaba, ọmọbirin
Abihaili, ati Mordekai, ara Juda, fi ọla
gbogbo kọwe, lati fi idi iwe keji ti Purimu
yi mulę.
30 O si fi iwe ranşę si gbogbo awọn Ju,
si ętadilã̀doje ìgberiko ijọba Ahasweri, ọ̀rọ
alafia ati otitọ.
31 Lati fi idi ọjọ Purimu wọnyi mulę, li
akokò wọn ti a yàn gęgę bi Mordekai, ara
Juda, ati Esteri ayaba ti paşę fun wọn, ati
bi nwọn ti pinnu rę̀ fun ara wọn, ati fun
iru-ọmọ wọn, ọ̀ran ã̀wę ati ękún wọn.
32 Aşę Esteri si fi idi ọ̀ran Purimu yi
mulę; a si kọ ọ sinu iwe.

## ORI 10.

AHASWERUSI ọba si fi owo ọba le ilę
fun gbogbo ilę, ati gbogbo erekùşu
okun.
2 Ati gbogbo işe agbara rę̀, ati ti ipa rę̀,
ati ìrohin titobi Mordekai, bi ọba ti sọ ọ di
nla, a kò ha kọ wọn sinu iwe ọ̀rọ ọjọ awọn
ọba Media ati Persia?
3 Nitori Mordekai ara Juda li o şe ibi-
keji Ahaswerusi ọba, o si tobi ninu awọn
Ju, o si şe itęwọgbà lọdọ ọ̀pọlọpọ ninu
awọn arakọnrin rę̀, o nwá ire awọn enia rę̀,
o si nsọ̀rọ alafia fun gbogbo awọn iru-ọmọ
rę̀.

Digitized by Google

IWE

# JOBU.

## ORI 1.

OKỌNRIN kan wà ni ilẹ Usi, orukọ ẹniti ijẹ Jobu; ọkọnrin na si ṣe olõtọ, o duro ṣinṣin, ẹniti o si bẹ̀ru Ọlọrun, ti o si korira ìwa buburu.

2 A si bi ọmọkọnrin meje ati ọmọbirin mẹta fun u.

3 Ohunọ̀sin rẹ̀ si jẹ ẹdẹgbarin agutan, ati ẹgbẹdogun ibakasiẹ, ati ẹdẹgbẹta ajaga ọdámalu, ati ẹdẹgbẹta abokẹtẹkẹtẹ, o si pọ̀; bẽli ọkọnrin yi si pọ̀ jù gbogbo awọn ọmọ ara ila-õrun lọ.

4 Awọn ọmọ rẹ̀ a si ma lọ ijẹun àse ninu ile ara wọn, olukuluku li ọjọ rẹ̀; nwọn a si ma ranṣẹ pe arabirin wọn mẹtẹta lati jẹun ati lati mu pẹlu wọn.

5 O si ṣe, nigbati ọjọ àse wọn pé yika, ni Jobu ranṣẹ lọ iyà wọn si mimọ, o si dide ni kùtukutu owurọ, o si rú ẹbọ sisun niwọn iye gbogbo wọn; nitoriti Jobu wipe; bọya awọn ọmọ mi ti ṣẹ̀, nwọn kò si ṣọpẹ̀ fun Ọlọrun lọkàn wọn. Bẽni Jobu imaṣe nigbagbogbo.

6 Njẹ, o di ọjọ kan, nigbati awọn ọmọ Ọlọrun wá ipé niwaju Oluwa, Satani si wá pẹlu wọn.

7 Oluwa si bi Satani wipe: nibo ni iwọ ti wá? nigbana ni Satani da Oluwa lohùn wipe: ni ilọ siwá sẹhin lori ilẹ aiye, ati ni irinkerindo ninu rẹ̀.

8 Oluwa si sọ fun Satani pe, Iwọ ha kiyesi Jobu iranṣẹ mi, pe, kò si ekeji rẹ̀ li aiye, ọkọnrin ti iṣe olõtọ, ti o si duro ṣinṣin, ẹniti o bẹ̀ru Ọlọrun, ti o si korira ìwa buburu.

9 Nigbana ni Satani dá Oluwa lohùn wipe: Jobu ha bẹ̀ru Oluwa li asan bi?

10 Iwọ kò ha ti sọgbà yi i ká, ati yi ile rẹ̀ ati yi ohun ti o ni ká ni iha gbogbo? Iwọ busi iṣẹ ọwọ rẹ̀, ohunọ̀sin rẹ̀ si npọsi i ni ilẹ.

11 Njẹ nawọ rẹ nisisiyi, ki o si fi tọ́ ohun gbogbo ti o ni; bi kì yio si bọhùn li oju rẹ.

12 Oluwa si dá Satani lohùn wipe: kiyesi i, ohun gbogbo ti o ni mbẹ ni ikawọ rẹ, kìki on tikara rẹ̀ ni iwọ kò gbọdọ̀ fi ọwọ rẹ kàn: bẽni Satani jade lọ kuro niwaju Oluwa.

13 O si di ọjọ kan, nigbati awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin ati obirin njẹ, ti nwọn nmu ọti-waini ninu ile ẹgbọn wọn ọkọnrin:

14 Onṣẹ kan si tọ̀ Jobu wá wipe: awọn ọda-malu ntulẹ, awọn kẹtẹkẹtẹ si njẹ li ẹba wọn;

15 Awọn ara Saba si kọlu wọn, nwọn si nkó wọn lọ, pẹlupẹlu nwọn ti fi idà ṣá awọn iranṣẹ pa, emi nikanṣoṣo li o sa asalà lati ròhin fun ọ.

16 Bi o ti nsọ li ẹnu; ẹnikan de pẹlu ti o si wipe: iná nla Ọlọrun ti ọrun bọ́ si ilẹ, o si jó awọn agutan ati awọn iranṣẹ ni ajorun; emi nikanṣoṣo li o salà lati rohin fun ọ.

17 Bi o si ti nsọ li ẹnu, ẹnikan si de pẹlu ti o wipe: awọn ara Kaldea pingun si ọna mẹta, nwọn si kọlu awọn ibakasiẹ, nwọn si kó wọn lọ, pẹlupẹlu nwọn si fi idà ṣá awọn iranṣẹ pa; emi nikanṣoṣo li o sa asalà lati rohin fun ọ.

18 Bi o ti nsọ li ẹnu, ẹnikan de pẹlu ti o si wipe: awọn ọmọ rẹ ọkọnrin ati ọmọ rẹ obirin njẹ nwọn nmu ọti-waini ninu ile ẹgbọn wọn ọkọnrin.

18 Si kiyesi i, ẹfufu nlanla ti iha ijù fẹ wá ikọlu igun mẹrẹrin ile, o si wolù awon ọdọmọkọnrin na, nwọn si kú, emi nikanṣoṣo li o yọ lati rohin fun ọ.

20 Nigbana ni Jobu dide, o si fa aṣọ igunwa rẹ̀ ya, o si fari rẹ̀, o wolẹ, o si gbadura.

21 Wipe, Nihoho ni mo ti inu iya mi jade wá, nihoho ni emi o si tun pada lọ sibẹ: Oluwa fifunni Oluwa si gbà lọ, ibukun li orukọ Oluwa.

22 Ninu gbogbo eyi Jobu kò ṣẹ̀, bẽni kò si fi were pè Ọlọrun lẹjọ.

## ORI 2.

OSI tun di ijọ kan nigbati awọn ọmọ
Ọlọrun wá ipé niwaju Oluwa, Satani si
wá pẹlu wọn, lati pé niwaju Oluwa.
2 Oluwa si bi Satani pe, nibo ni iwọ ti
wá? Satani si dá Oluwa lohùn pe, lati ilọ
siwá sẹhin lori ilẹ aiye ati ni irinkerindo
ninu rẹ̀.
3 Oluwa si wi fun Satani pe, iwọ ha
kiyesi Jobu iranṣẹ mi, pe, kò si ekeji rẹ̀ li
aiye, ọkọnrin ti iṣe olõtọ ti o si duro ṣinṣin,
ẹniti o bẹru Ọlọrun ti o si korira ìwa buburu,
bẹ̃li o si di ìwa otitọ rẹ̀ mu ṣinṣin, bi
iwọ tilẹ ti dẹ mi si i lati run u lainidi.
4 Satani si dá Oluwa lohùn wipe, awọ
fun awọ; ani ohun gbogbo ti enia ni, on
ni yio fi rà ẹmi rẹ̀.
5 Ṣugbọn nawọ rẹ nisisiyi, ki o si fi tọ́
egungun rẹ̀ ati ara rẹ̀, bi kì yio si bọhùn li
oju rẹ.
6 Oluwa si wi fun Satani pe, Wõ, o mbẹ
ni ikawọ rẹ, ṣugbọn dá ẹmi rẹ̀ si.
7 Bẹ̃ni Satani jade lọ kuro niwaju Oluwa,
o si sọ Jobu li õwo kikankikan lati
atẹlẹsẹ rẹ̀ lọ de atari rẹ̀.
8 O si mu apadì o fi nhá ara rẹ̀, o si joko
ninu ẽru.
9 Nigbana ni aya rẹ̀ wi fun u pe, iwọ di
ìwa otitọ rẹ mu sibẹ! bu Ọlọrun, ki o si ku.
10 Ṣugbọn on da a lohùn pe, iwọ sọ̀rọ bi
ọkan ninu awọn obirin alaimoye ti isọ̀rọ;
kinla! awa o ha gba ire lọwọ Ọlọrun, ki a
má si gba ibi! Ninu gbogbo eyi Jobu kò
fi ète rẹ̀ ṣẹ̀.
11 Nigbati awọn ọrẹ Jobu mẹta gburo
gbogbo ibi ti o ba a, nwọn wá, olukuluku
lati ibujoko rẹ̀ wá; Elifasi, ara Tema, ati
Bildadi, ara Ṣua, ati Sofari, ara Naama:
nitoripe nwọn ti dajọ ipade pọ̀ lati ba a
ṣọ̀fọ on ati ṣipẹ fun u.
12 Nigbati nwọn si gboju wọn wò li
òkere rére, ti nwọn kò si mọ̀ ọ, nwọn gbe
ohùn wọn soke, nwọn sọkun: olukuluku si
fa aṣọ igunwa rẹ̀ ya, nwọn si kù erupẹ si
oju ọrun si ara wọn lori.
13 Bẹ̃ni nwọn joko tì i ni ilẹyilẹ ni ijọ
meje ti ọ̀san ti oru, ẹnikẹni kò si ba a dá
ọ̀rọ kan sọ nitoriti nwọn ri pe, ibinujẹ rẹ̀
pọ̀ gidigidi.

## ORI 3.

LẸHIN eyi ni Jobu yanu o si fi ọjọ ibi
rẹ̀ ré.
2 Jobu sọ, o si wipe,
3 Ki ọjọ ti a bi mi ki o di igbagbe, ati
oru nì, ninu eyi ti a wipe; a loyun ọmọkọnrin kan.
4 Ki ọjọ na ki o jasi òkunkun, ki Ọlọrun
ki o má ṣe kà a si lati ọrun wá, bẹ̃ni
ki imọlẹ ki o máṣe mọ́ si i.
5 Ki òkunkun ati ojiji ikú fi ṣe ti ara
wọn: ki awọsanma ki o bà le e, ki iṣúdudu
ọjọ na ki o pa a laiya.
6 Ki òkunkun ki o ṣúbo oru na biribiri,
ki o má ṣe yọ̀ pẹlu ọjọ ọdun na: ki a má
ṣe kà a mọ iye ọjọ oṣù.
7 Ki oru na ki o yàgan; ki ohùn ayọ̀
kan ki o má ṣe wọnu rẹ̀ lọ.
8 Ki awọn ti ifi ọjọ gegun ki o fi i gegun,
ti nwọn muratan lati rú Lefiatani soke.
9 Ki irawọ̀ ofẽfe ọjọ rẹ̀ ki o ṣokùnkun;
ki o ma wá imọlẹ, ṣugbọn ki o má si, bẹ̃ni
ki o má ṣe ri afẹmọjumọ́.
10 Nitoriti kò se ilẹkun inu iya mi, bẹ̃ni
kò si pa ibinujẹ mọ́ kuro li oju mi.
11 Ẽṣe ti emi kò fi kú lati inu wá, tabi
ti emi kò fi pin ẹmi nigbati mọ ti inu jade
wá?
12 Ẽṣe ti ẽkun wá pade mi, tabi ọmu ti
emi o mu?
13 Njẹ! nisisiyi, emi iba ti dubulẹ̀ jẹ,
emi a si dakẹ, emi iba ti sùn: njẹ emi iba
ti simi!
14 Pẹlu awọn ọba ati igbimọ aiye, ti o
mọle takete fun ara wọn.
15 Tabi pẹlu awọn ọmọ-alade ti o ni
wura, ti nwọn si fi fadakà kún inu ile
wọn.
16 Tabi bi ọlẹ̀ ti a sin, emi kì ba ti si;
bi ọmọ iṣẹnu ti kò ri imọlẹ.
17 Nibọ ni ẹni-buburu ṣiwọ iyọnilẹnu,
nibẹ ẹni-ãrẹ wà ninu isimi.
18 Nibẹ ni awọn ìgbekun simi pọ̀, nwọn
kò si gbohùn amunisin mọ́.
19 Ati ewe ati àgba wà nibẹ, ẹru si di
omnira kuro lọwọ olowo rẹ̀.
20 Nitori kili a ṣe fi imọlẹ fun otoṣi, ati
ìye fun ọlọkàn kikoro.
21 Ti nwọn duro de ikú, ṣugbọn on kò
wá, ti nwọn wàlẹ wá a jù fun iṣura ti a bò
mọlẹ pamọ.
22 Ẹniti o yọ̀ gidigidi, ti inu wọn si dùn
nigbati nwọn ba le wá isa-okú ri.
23 Kili a fi imọlẹ fun ẹniti ọ̀na rẹ̀ lumọ
si, ti Ọlọrun si sọgba di mọ ká?
24 Nitoripe imi-ẹ̀dun mi ṣaju ki nto
jẹun, ikerora mi si tú jade bi omi.
25 Nitoripe ohun na ti mo bẹ̀ru gidigidi
li o de ba mi yi, ẹ̀ru ohun ti mọ bà li o si
de si mi yi.
26 Emi kò wà lailewu rí, bẹ̃li emi kò ni



Digitized by Google

isimi, bẹ̃li emi kò ni ìfaiyabalẹ, asiwá-
asibọ̀ iyọnu de.

## ORI 4.

NIGBANA ni Elifasi, ara Tema, dahùn
wipe,
2 Bi awa ba fi ẹnu le e, lati ba ọ sọrọ,
iwọ o ha binujẹ? ṣugbọn tali o le pa ọ̀rọ
mọ ẹnu laisọ?
3 Kiyesi i, iwọ sa ti kọ́ ọ̀pọ enia, iwọ sa
ti mu ọwọ alailera le.
4 Ọ̀rọ rẹ ti gbe awọn ti nṣubu lọ duro,
iwọ si ti mu ẽkun awọn ti nwarìrì lera.
5 Ṣugbọn nisisiyi o de ba ọ, o si rẹ̀ ọ, o
kọlu ọ, ara rẹ kò lelẹ̀.
6 Ìbẹru Ọlọrun rẹ kò ha jẹ igbẹkẹle rẹ?
ati iduroṣinṣin si ìwa ọ̀na rẹ kò ha si jẹ
abá rẹ?
7 Emi bẹ̀ ọ ranti, tali o ṣegbe ri laiṣẹ̀,
tabi nibo li a gbe ké olododo kuro ri?
8 Ani bi emi ti ri rí pe: awọn ti nṣe
itulẹ ẹ̀ṣe, ti nwọn si fọ́n irugbin ìwa buburu,
nwọn a si ká eso rẹ̀ na.
9 Nipa ifẹsi Ọlọrun nwọn a ṣegbe, nipa
ẽmi ibinu rẹ̀ nwọn a parun.
10 Bibu ramuramu kiniun ati ohùn
onroró kiniun ati ehin awọn ẹ̀gbọrọ kiniun
li a ka.
11 Ogbo kiniun kúgbe, nitori airi ohun-
ọdẹ, awọn ẹ̀gbọrọ kiniun sisanra li a tuka-
kiri.
12 Njẹ nisisiyi a fi ohun lilumọ́ kan hàn
fun mi, eti mi si gbà diẹ ninu rẹ̀.
13 Ni iro inu loju iran oru, nigbati orun
ìjika kun enia.
14 Ẹru bà mi ati iwarìrì ti o mu gbogbo
egungun mi wá pepé.
15 Nigbana ni iwin kan kọja lọ niwaju
mi, irun ara mi dide ró ṣanṣan.
16 On duro jẹ, ṣugbọn emi kò le iwò
apẹrẹ irí rẹ̀, àworan kan hàn niwaju mi,
idakẹ rọrọ wà, mo si gbohùn kan wipe:
17 Ẹni kikú le jẹ olododo niwaju Ọlọrun,
enia ha le mọ́ ju Ẹlẹda rẹ̀ bi?
18 Kiyesi i, on kò gbẹkẹlẹ awọn iranṣẹ
rẹ̀, ninu awọn angeli rẹ̀ ni o si ri ẹ̀ṣẹ.
19 Ambọtori awọn ti ngbe inu ile amọ̀;
ẹniti ipilẹ wọn jasi erupẹ ti yio di rírun
kòkoro.
20 A npa wọn run lati òwurọ di alẹ́,
nwọn gbe lailai lairi ẹni kà a si.
21 A kò ha ke okùn iye wọn kuro bi?
nwọn ku, ani lailọgbọn.

## ORI 5.

NJẸ pè nisisiyi! bi ẹnikan ba wà ti yio
da ọ lohùn, tabi tani ninu awọn ẹni-
mimọ́ ti iwọ o wò?
2 Nitoripe ibinu pa alaimoye, irúnu a si
pa òpe enia.
3 Emi ti ri alaimoye ti o ta gbongbò
mulẹ̀, ṣugbọn lojukanna mo fi ibujoko rẹ̀
bú.
4 Awọn ọmọ rẹ̀ kò jina sinu ewu, a si
tẹ̀ wọn mọlẹ loju ibode, bẹ̃ni kò si alãbò
kan.
5 Ikore oko ẹniti awọn ẹniti ebi npa
jẹrun, ti nwọn si wọnú ẹ̀gun lọ ikó, awọn
igara si gbe ohùn ini wọn mì.
6 Bi ipọnju kò tilẹ̀ tinu erupẹ jade wá
ni, ti iyọnu kò si tinu ilẹ hù jade wá.
7 Ṣugbọn a bi enia sinu wàhala, gẹgẹ bi
ìpẹpẹ iná ti ima ta sokè.
8 Sọdọ Ọlọrun li emi lè ma ṣe awári, li
ọwọ Ọlọrun li emi lè ma fi ọ̀ran mi le.
9 Ẹniti o ṣe ohun ti o tobi, ti a kò lè iṣe
awári, ohun iyanu laini iye.
10 Ti nrọ̀jo si ilẹ aiye, ti o si nrán ọmi
sinu ilẹ̀kilẹ.
11 Lati gbe awọn onirẹlẹ leke, ki a le
igbé awọn ẹni ibinujẹ ga si ibi ailewu.
12 O yi ìmọ awọn alarekerekè po, bẹ̃li
ọwọ wọn kò lè imu idawọle wọn-ṣẹ.
13 O mu awọn ọlọgbọ́n ninu arekereke
ara wọn, ati ìmọ awọn onroro li o tãri
ṣubu li ògedengbè.
14 Nwọn sure wọ inu òkunkun li ọ̀san,
nwọn si nfọwọ talẹ̀ li ọ̀sangangan bi ẹnipe
li oru.
15 Ṣugbọn o gba talakà là kuro li ọwọ
idà, lọwọ ẹnu wọn, ati lọwọ awọn alagbara.
16 Bẹ̃ni abá wà fun talaka, aiṣotitọ si pa
ẹnu rẹ̀ mọ.
17 Kiyesi i, ibukún fun li ẹniti Ọlọrun
bawi, nitorina ni má ṣe gan ìbawi Olodu-
mare.
18 Nitoripe on a mu ni lara kan, a si di
idi itura, o ṣa lọgbẹ, ọwọ rẹ̀ a si mu jina.
19 Yio gbà ọ ninu ipọnju mẹfa, ani ninu
meje ibi kan kì yio ba ọ.
20 Ninu ìyan yio gbà ọ lọwọ ikú, ati
ninu ogun yio gbà ọ lọwọ idà.
21 A o pa ọ mọ kuro lọwọ ìna ahọn, bẹ̃ni
iwọ kì yio bẹru iparun nigbati o ba dé.
22 Ẹrin iparun ati ti iyàn ni iwọ o rín,
bẹ̃ni iwọ kì yio bẹru ẹranko ilẹ aiye.
23 Nitoripe iwọ o ba okuta ìgbẹ mulẹ̀,
awọn ẹranko ìgbẹ yio wà pẹlu rẹ li alafia.
24 Iwọ o si mọ̀ pe alafia ni ibujoko rẹ

Digitized by Google

wà, iwọ o si ma ṣe ibẹ̀wo ibujoko rẹ, iwọ
kì yio ṣìna.
25 Iwọ o si mọ̀ pẹlu pe iru-ọmọ rẹ yio si
pọ̀, ati awọn ọmọ-ọmọ rẹ yio ri bi koriko
ìgbẹ.
26 Iwọ o wọ isa-okú rẹ lọ li ògbologbo
ọjọ bi apo-ọka ti o gbó, ti a si nko ni igbà
ikore rẹ̀.
27 Kiyesi i, awa ti nwadi rẹ̀, bẽli o ri!
gbà a gbọ́, ki o si mọ̀ pe fun ire ara rẹ ni!

ORI 6.

JOBU si dahùn o si wipe,
2 A! a ba le iwọn ibinujẹ mi ninu
òṣuwọn, ki a si le igbe ọ̀fọ mi le ori ọ̀ṣuwọn
ṣọkan pọ̀!
3 Njẹ nisisiyi, iba wuwo jù iyanrin okun
lọ: nitorina li ọ̀rọ mi ṣe ntàse.
4 Nitoripe ọfa Olodumare wọ̀ mi ninu,
oró eyiti ọkàn mi mu; ipaiya-ẹ̀ru Ọlọrun
dotì mi.
5 Kẹtẹkẹtẹ ìgbẹ a ma dún, nigbati o ba
ni koriko, tabi ọdá-malu a ma dún sori ijẹ
rẹ̀?
6 A le jẹ ohun ti kò li adùn li aini iyọ̀,
tabi adùn wà ninu funfun ẹyin?
7 Ohun ti ọkàn mi kọ̀ lati tọ́, on li o
dàbi onjẹ mi ti kò ni adùn.
8 A! emi iba lè ri iberè mi gbà; ati pe,
ki Ọlọrun le fi ohun ti emi ṣafẹri fun mi.
9 Ani, Ọlọrun iba jẹ pa mi run, ti on
iba jẹ ṣiwọ rẹ̀ ki o si ké mi kuro.
10 Nigbana ni emi iba ni itunú sibẹ, ani
emi iba mu ọkàn mi le ninu ibinujẹ mi ti
kò da ni si: nitori emi kò fi ọ̀rọ Ẹni Mimọ́
nì sin ri.
11 Kili agbara mi ti emi o fi dabá? ki
si li opin mi ti emi o fi fà ẹmi mi gùn?
12 Agbara mi iṣe agbara okuta bi, tabi
ẹran-ara mi iṣe idẹ?
13 Iranlọwọ mi kò ha wà ninu mi:
ọgbọn ha ti salọ kuro lọdo mi bi?
14 Ẹniti aya rẹ̀ yọ́ danu tan ni a ba ma-
ṣãnu fun lati ọdọ ọrẹ rẹ̀ wá, ki o má kọ̀
ibẹru Olodumare silẹ̀.
15 Awọn ará mi ṣẹ̀tan bi odò ṣolõ, bi
iṣàn gburu omi odò ṣolõ, nwọn ṣàn kọja lọ.
16 Ti o dúdu nitori omi didì, ati nibiti
òjo didì gbe lúmọ si.
17 Nigbakũgba ti nwọn ba gboná, nwọn
a si yọ́ ṣanlọ, nigbati õrùn ba mú, nwọn si
gbẹ kurò ni ipò wọn.
18 Iya ọ̀na wọn a si yipada sapakan,
nwọn goke si ibi asan, nwọn si run.
19 Ẹgbẹ ogun Tema nwoye, awọn ọwọ́-
èro Seba duro de wọn.
20 Nwọn dãmu, nitoriti nwọn ni abá;
nwọn debẹ̀, nwọn si dãmu.
21 Njẹ nisisiyi, ẹnyin dabi wọn; ẹnyin
ri irẹ̀silẹ mi, aiya si fò nyin.
22 Emi ha wipe, ẹ mu ohun fun mi wá,
tabi pe, ẹ bun mi ni ẹ̀bun ninu ohun ini
nyin?
23 Tabi, ẹ gbà mi li ọwọ ọ̀ta nì, tabi, ẹ
rà mi padà kuro lọwọ alagbara nì!
24 Ẹ kọ́ mi, emi o si pa ẹnu mi mọ́; ki
ẹ si mu mi moye ibiti mo gbe ti ṣìna.
25 Wo! bi ọ̀rọ otitọ ti li agbara to!
ṣugbọn kini aròye ibawi nyin jasi?
26 Ẹnyin ṣebi ẹ o ba ọ̀rọ ati ohùn ẹnu
ẹniti o taku wi, ti o dabi afẹfẹ.
27 Ani ẹnyin ṣẹ́ gege fun alainibaba,
ẹnyin si da iye le ọrẹ nyin.
28 Nitorina ki eyi ki o tó fun nyin: ẹ
ma wò mi! nitoripe o hàn gbangba pe: li
oju nyin ni emi kì yio ṣeke.
29 Emi bẹ nyin, ẹ pada, ki o má ṣe jasi
ẹ̀ṣẹ: ani ẹ si tun pada, are mi mbẹ ninu
ọ̀ran yi.
30 Aiṣedede ha wà li ahọn mi? njẹ
itọwò ẹnu mi kò kuku le imọ̀ ohun ti o
burujù?

ORI 7.

NJẸ ija kan kò ha si fun enia lori ilẹ, ọjọ
rẹ̀ pẹlu kò dabi ọjọ alagbaṣe?
2 Bi ọmọ-ọdọ ti ima kanju bojuwo ojiji,
ati bi alagbaṣe ti ima kanju wọ̀na owo iṣẹ rẹ̀.
3 Bẽli a mu mi ni oṣoṣu asan, oru idani-
lagã ni a si là silẹ fun mi.
4 Nigbati mo dubulẹ̀, emi wipe, nigbawo
ni emi o dide, ti oru yio si kọja? o si tó
fun mi lati yi sihin yi sọhun titi yio fi di
afẹmọ́jumọ.
5 Kòkoro ati ogulùtu erupẹ li a fi wọ̀ mi
li aṣọ, àwọ mi bù, o si di sisun ni.
6 Ọjọ mi yara jù ọkọ̀ iwunṣọ lọ, o si di
lilò li ainireti.
7 A! ranti pe afẹfẹ li ẹmi mi; oju mi
kì yio pada ri rere mọ.
8 Oju ẹniti o ri mi, kì yio ri mi mọ;
oju rẹ tẹ mọra mi, emi kò si mọ́!
9 Bi awọ-sanma ti iparun, ti isi fò lọ,
bẽli ẹniti nlọ si ipò-okú, ti kì yio pada
wá mọ.
10 Kì yio pada sinu ile rẹ̀ mọ, bẽni ipò
rẹ̀ kì yio mọ̀ ọ mọ.
11 Nitorina emi kì yio pa ẹnu mi mọ,
emi o ma sọ ninu irora ọkàn mi, emi o ma
ṣe irahùn ninu kikoro ọkàn mi.
12 Emi ama iṣe ejo okun tabi erinmi, ti
iwọ fi yàn oluṣọ tì mi?

Digitized by Google

13 Nigbati mo wipe, ibusùn mi yio tù
mi lara, itẹ mi yio gbé ẹrù irahùn mi pẹlu.
14 Nigbana ni iwọ fi alá da mi niji, iwọ
si fi iran oru dẹrubà mi.
15 Bẽli ọkàn mi yan sisokú jù aye, ikú
jù egungun mi lọ.
16 O su mi, emi kò le wà titi: jọwọ mi
jẹ, nitoripe asan li ọjọ mi.
17 Kili enia ti iwọ o ma kokìki rẹ̀? ati
ti iwọ iba fi gbe ọkàn rẹ le e?
18 Ati ti iwọ o fi ma wa ibẹ̀ ẹ wò li oro-
wurọ̀, ti iwọ o si ma dán a wò nigbakũgba!
19 Yio ti pẹ́ to ki iwọ ki o to fi mi silẹ̀
lọ, ti iwọ o fi jọ mi jẹ titi emi o fi le dá itọ
mi mì.
20 Emi ti ṣẹ̀, kili emi o ṣe si ọ, iwọ Olù-
tọju enia? ẽṣe ti iwọ fi fi mi ṣe àmi itasi
niwaju rẹ, bẽli emi si di ẹrù-wuwo si ara rẹ?
21 Ẽṣe ti iwọ kò si dari irekọja mi jì,
ki iwọ ki o si mu aiṣedede mi kuro? njẹ
nisisiyi li emi iba sùn ninu erupẹ, iwọ iba
si wá mi kiri li owurọ̀, emi ki ba ti si.

## ORI 8.

NIGBANA ni Bildadi, ara Ṣua, dahùn
wipe,
2 Iwọ o ti ma sọ nkan wọnyi pẹ to? ti
ọ̀rọ ẹnu rẹ yio si ma dabi ẹfufu nla?
3 Ọlọrun a ha ma yi idajọ po bi, tabi
Olodumare a ma fi otitọ ṣẹ̀ bi?
4 Nigbati awọn ọmọ rẹ ṣẹ̀ si i, o si gbà
wọn kuro nitori irekọja wọn.
5 Bi iwọ ba si kepe Ọlọrun ni igba ako-
kò, ti iwọ bá si gbadura ẹ̀bẹ si Olodumare.
6 Iwọ iba mọ́, ki o si dúro ṣinṣin: njẹ
nitõtọ nisisiyi on o tají fun ọ, on a si sọ
ibujoko ododo rẹ di pipọ.
7 Ipilẹṣẹ rẹ iba tilẹ kere ri, bẽni igbẹhin
rẹ iba pọ̀ si i gidigidi.
8 Emi bẹ̀ ọ njẹ, bere lọwọ awọn ara
igbãni, ki o si kiyesi iwádi awọn baba wọn.
9 Nitoripe ọmọ-àná li awa, a kò si mọ̀
nkan, nitoripe òjiji li ọjọ wa li aiye.
10 Awọn kì yio ha kọ́ ọ, nwọn kì yio si
sọ fun ọ, nwọn kì yio si sọ̀rọ lati inu ọkàn
wọn jade wá?
11 Koriko odò ha le dàgba laini ẹrẹ̀, tabi
ẽsú ha le dàgba lailomi?
12 Nigbati o wà ni tutù, ti a kò ke e
lulẹ̀, o rọ danu sin eweko miran gbogbo.
13 Bẽni ipa ọ̀na gbogbo awọn ti o gba-
gbe Ọlọrun, abá awọn àgabàgebe yio di ofo.
14 Abá ẹniti a o ke kuro, ati igbẹkẹle
ẹniti o dàbi ile alantakùn.
15 Yio fi ara tì ile rẹ̀, ṣugbọn kì yio le
iduro, yio fi di ara rẹ̀ mu ṣinṣin ṣugbọn kì
yio le iduro pẹ.
16 O tutù niwaju õrùn, ẹka rẹ̀ si yọ jade
ninu ọgbà rẹ̀.
17 Gbòngbo rẹ̀ ta yi ebè ka, o si wò ibi
okuta wọnni.
18 Bi o ba si pa a run kuro ni ipò rẹ̀,
nigbana ni ipò na yio sẹ ẹ pe: emi kò ri ọ
ri!
19 Kiyesi eyi ni ayọ̀ ọ̀na rẹ̀ ati lati inu
ilẹ li omiran yio ti hù jade wá.
20 Kiyesi i, Ọlọrun kì yio ta ẹni-otitọ
nù, bẽni kì yio ràn oniwa-buburu lọwọ.
21 Titi yio fi fi ẹ̀rin kún ọ li ẹnu, ati ète
rẹ pẹlu iho ayọ̀.
22 Itiju li a o fi bò awọn ti o korira rẹ,
ati ibujoko enia buburu kì yio si mọ.

## ORI 9.

JOBU si dahùn o si wipe,
2 Emi mọ̀ pe bẽni nitõtọ! bawo li enia
yio ha ti ṣe alare niwaju Ọlọrun?
3 Bi o ba ṣepe yio ba a jà, on kì yio lè
idá a lohùn kan ninu ẹgbẹrun ọ̀ran.
4 Ọlọgbọ́n-ninu ati alagbara ni ipá li on;
tali o ṣagidi si i, ti o si gbè fun u ri?
5 Ẹniti o ṣi okè ni idi, ti nwọn kò si
mọ̀: ti o tari wọn ṣubu ni ibinu rẹ̀.
6 Ti o mì ilẹ aiye tìti kuro ni ipò rẹ̀,
ọwọ̀n rẹ̀ si mì tìti.
7 Ti o paṣẹ fun õrùn, ti on kò si là, ti o
si dí irawọ̀ mọ́.
8 On nikanṣoṣo li o na oju ọrun lọ, ti o
si nrìn lori ìgbì okun.
9 Ẹniti o da irawọ̀ Arketuru, Orioni ati
Pleiade ati iyàra pipọ ti gusu.
10 Ẹniti nṣe ohun ti o tobi jù awari lọ,
ani ohun iyanu laini iye.
11 Kiyesi i, on kọja lọ li ẹ̀ba ọdọ mi, emi
kò si ri i, o si kọja siwaju, bẽli emi kò ri
oju rẹ̀.
12 Kiyesi i, o jãgbà lọ, tani yio da a
pada? tani yio bi i pe, kini iwọ nṣe nì?
13 Ọlọrun kò ni fà ibinu rẹ̀ sẹhin, awọn
oniranlọwọ ìgberaga a si tẹriba labẹ rẹ̀.
14 Ambọtori emi ti emi o fi dá a lohùn,
ti emi o fi má ṣa ọ̀rọ awawí mi ba a ṣawiye?
15 Bi o tilẹ ṣepe mo ṣe olododo, emi kò
gbọdọ̀ da a lohùn, ṣugbọn emi o gbadura
ẹ̀bẹ mi sọdọ onidajọ mi.
16 Bi emi ba si kepè e, ti on si da mi
lohùn, emi kì yio si gbagbọ pe, on ti feti
si ohùn mi.
17 Nitoripe o fi ẹ̀fufu nla ṣẹ mi tutu, o
sọ ọgbẹ mi di pipọ lainidi.

Digitized by Google

On kì yio jẹ ki emi ki o fà ẹmi mi,
n o fi ohun kikorò kún u fun mi.
Bi mo ba sọ ti agbara, wò o! alagbara
bi niti idajọ, tani yio da akoko fun
i rò?
Bi mo tilẹ da ara mi lare, ẹnu ara mi
dá mi lẹbi; bi mo wipe, olododo
, yio si fi mi hàn ni ẹni-òdi.
Olõtọ ni mo ṣe, sibẹ emi kò kiyesi
i, ìwa mi li emi iba ma gàn.
Ohun kanna ni, nitorina ni emi ṣe sọ
a pa ẹni-otitọ ati enia buburu pẹlu.
Bi jamba ba pa ni lojijì, yio rẹrin
o alaiṣẹ̀.
A fi aiye le ọwọ enia buburu; o si bò
onidajọ rẹ̀ li oju; bi kò ba ri bẹ̃, njẹ

Njẹ nisisiyi ọjọ mi yara jù onṣẹ lọ,
fò lọ, nwọn kò ri ire.
Nwọn kọja lọ bi ọkọ-ẽsú ti nsure lọ;
ti o nyara si ohun ọdẹ.
Bi emi ba wipe, emi o gbagbe aro
jẹ mi, emi o fi ọkàn lelẹ̀, emi o si rẹ̀
i lẹkun.
Ẹru ibinujẹ mi gbogbo bà mi, emi
e iwọ kì yio mu mi bi alaiṣẹ̀.
Bi o ba ṣepe enia buburu li emi, njẹ
mi nṣe lãlã lasan si!
Bi mo tilẹ fi omi òjo didì wẹ̀ ara mi,
fi omi-aró wẹ̀ ọwọ mi mọ́,
Sibẹ iwọ o gbe mi bọ̀ inu ihò ọ̀gọdọ,
ra mi yio sọ mi di ẹni-irira.
Nitori on kì iṣe enia bi emi, ti emi o
a lohùn, ti awa o fi pade ni idajọ.
Bẽni kò si alatunṣe kan lagbedemeji
ti iba fi ọwọ rẹ̀ le awa mejeji lara.
Ki on sa mu ọ̀pa rẹ̀ kuro lara mi, ki
u rẹ̀ ki o má si ṣe daiya fò mi.
5 Nigbana ni emi iba sọ̀rọ, emi kì ba
ẹru rẹ̀; ṣugbọn kò ri bẹ̃ fun mi.

## ORI 10.

ARA ìwa aiye mi da mi tan, emi o tú
aroye mi sode lọdọ mi, emi o ma sọ
u kikorò ibinujẹ ọkàn mi.
Emi o wi fun Ọlọrun pe, o jare! máṣe
mi lẹbi; fi hàn mi nitori idi ohun ti
fi mba mi jà.
O ha tọ́ si ọ ti iwọ iba ma tẹ̀mọlẹ̀, ti
iba fi ma gan iṣẹ ọwọ rẹ, ti iwọ o fi ma
imọlẹ si ìmọ enia buburu?
Oju rẹ iha ṣe oju enia bi? tabi iwọ
a riran bi enia ti iriran?
5 Ọjọ rẹ ha dabi ọjọ enia, ọdun rẹ ha
i ọjọ enia?

6 Ti iwọ fi mbere aiṣedẽde mi, ti iwọ si
fi wa ẹ̀ṣẹ mi ri?
7 Iwọ mọ̀ pe emi kì iṣe oniwa-buburu,
kò si sí ẹniti igbà kuro li ọwọ rẹ.
8 Ọwọ rẹ li o ti dá mi, ti o si mọ mi
pọ̀ yikakiri; sibẹ iwọ si mbà mi jẹ́.
9 Emi bẹ̀ ọ ranti pe iwọ ti mọ mi bi
amọ̀; iwọ o ha si tun mu mi pada lọ sinu
erupẹ?
10 Iwọ kò ha ti tu mi dà jade bi wàra,
iwọ kò si mu mi dipọ̀ bi wàrakasi?
11 Iwọ sa ti fi awọ ati ẹran-ara wọ̀ mi,
iwọ si fi egungun ati iṣan ṣọgba yi mi ká.
12 Iwọ ti fun mi li ẹmi ati oju rere,
ibẹ̀wo rẹ si pa ọkàn mi mọ́.
13 Nkan wọnyi ni iwọ si ti fi pamọ
ninu rẹ; emi mọ̀ pe, eyi mbẹ lọdọ rẹ.
14 Bi mo ba ṣẹ̀, nigbana ni iwọ sàmi
si mi, iwọ kì yio si dari aiṣedede mi ji.
15 Bi mo ba ṣe ẹni-buburu, egbé ni fun
mi! bi mo ba si ṣe ẹni-rere, bẹ̃li emi kò
si le igbe ori mi soke. Emi dãmu, mo si
wo ipọnju mi.
16 Nitoriti npọ̀ si i: iwọ ndẹ mi kiri
bi kiniun; ati pẹlu, iwọ a si fi ara rẹ hàn
fun mi ni iyanju,
17 Iwọ si tun sọ awọn ẹlẹri rẹ si mi di
ọtun, iwọ si sọ irunu rẹ di pipọ si mi,
ayipada ati ogun dó tì mi.
18 Njẹ nitorina iwọ ha ṣe bí mi jade
lati inu wá? A! emi iba kúku ti kú,
ojukoju kì ba ti ri mi!
19 Emi iba dabi ẹniti kò si ri, a ba ti
gbe mi lati inu lọ si isà-okú.
20 Ọjọ mi kò ha kuru bi? dawọ duro,
ki o si jọwọ mi jẹ, ki emi fi aiya balẹ diẹ.
21 Ki emi ki o to lọ sibi ti emi kì yio
pada sẹhin mọ́, ani si ilẹ òkunkun ati ojiji
ikú.
22 Ilẹ òkunkun bi òkunkun tikararẹ̀,
ati ti ojiji ikú, laini ìto, nibiti imọlẹ dabi
òkunkun.

## ORI 11.

NIGBANA ni Sofari, ara Naama, dahùn
o si wipe,
2 A le iṣe ki a má ṣe dahùn si ọ̀pọlọpọ
ọ̀rọ, a ha si le dare fun ẹniti ẹnu rẹ̀ kún
fun ọ̀rọ sisọ.
3 Amọ̀tan rẹ le imu enia pa ẹnu wọn
mọ bi? bi iwọ ba yọṣuti si ni, ki ẹnikẹni
ki o má si doju tì ọ bi?
4 Nitori iwọ sa ti wipe, ọ̀rọ ẹkọ́ mi
mọ́, emi si mọ́ li oju rẹ.
5 Ṣugbọn o ṣe! Ọlọrun iba jẹ sọ̀rọ, ki
o si ya ẹnu rẹ̀ si ọ lara.

Digitized by Google

6 Ki o si fi aşiri ọgbọ́n hàn ọ pe, o pọ̀
jù oye enia lọ; nitorina mọ̀ pe: Ọlọrun
kò bere to bi ẹbi rẹ.
7 Iwọ ha le fi awari ri idi Ọlọrun? iwọ
le ri idi Olodumare de pipé rẹ̀?
8 O dabi giga ọrun, kini iwọ le işe? o
jinlẹ jù ipo-okú lọ, kini iwọ le imọ̀?
9 Iwọn rẹ̀ gùn jù aiye lọ, o si ni ìbu jù
okun lọ.
10 Bi on ba rekọja, ti o si sénà, tabi ti
o si şe ikojọpọ, njẹ, tani yio da a pada
kuro?
11 On sa mọ̀ enia asan, o ri ìwa-buburu
pẹlu, on kò si ni şe lãlã lati şà a rò.
12 Enia lasan a sa ma fẹ işe ọlọgbọ́n,
bi a tilẹ ti bi enia bi ọmọ kẹtẹkẹtẹ.
13 Bi iwọ ba tun ọkàn rẹ şe, ti iwọ si
nawọ rẹ sọdọ rẹ̀.
14 Bi aişedede kan ba mbẹ lọwọ rẹ, mu
u kuro si ọ̀na jijin réré, máşe jẹ ki iwàkiwa
ko wà ninu agọ rẹ.
15 Nigbana ni iwọ o gbe oju rẹ soke
laini abawọn, ani iwọ o duro şinşin, iwọ
kì yio si bẹ̀ru.
16 Nitoripe iwọ o gbagbe ọ̀şi rẹ, iwọ o
si ranti rẹ̀ bi omi ti o ti şàn kọja lọ.
17 Ọjọ aiye rẹ yio si mọlẹ jù ọsan
gangan lọ, bi okunkun tilẹ bò ọ mọlẹ
nisisiyi, iwọ o dabi owurọ̀.
18 Iwọ o si wà lailewu, nitoripe ireti
wà, ani iwọ o rin ile rẹ wò, iwọ o si simi
li alafia.
19 Iwọ o si dubulẹ pẹlu kì yio si sí
ẹniti yio dẹ̀ruba ọ, ani ọ̀pọ enia yio ma
wá oju-rere rẹ.
20 Şugbọn oju eniakenia yio mõfo, nwọn
kì yio le sala, ireti wọn a si dabi ẹniti o
jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ.

## ORI 12.

JOBU si dahùn o si wipe,
2 Kò si ani-ani nibẹ̀, şugbọn ẹnyin li
awọn enia na, ọgbọ́n yio si kú pẹlu nyin.
3 Şugbọn emi ni iyè ninu gẹgẹ bi ẹnyin:
emi kì işe ọmọ-ẹhin nyin: ani, tani kò
mọ̀ nkan bi iru wọnyi?
4 Emi dabi ẹniti a nfi şe ẹlẹya lọdọ
aladugbo rẹ̀, ti o kepe Ọlọrun, ti o si da
a lohùn: a nfi olõtọ ẹni-iduro-şinşin rẹrin
ẹlẹyá.
5 Ẹgan ni ẹni-ọ̀tọsi, ti ẹsẹ rẹ̀ mura tan
lati yọ́ ninu ìro ẹniti ara rọ̀.
6 Agọ awọn igara ngberú, awọn ti o si
nmu Ọlọrun binu wà lailewu, awọn ẹniti
o si gbá orişa mu li ọwọ wọn.
7 Şugbọn nisisiyi, bi awọn ẹrankọ lere,
nwọn o kọ́ ọ li ẹkọ́, ati ẹiyẹ oju ọrun,
nwọn o si sọ fun ọ.
8 Tabi, ba ilẹ aiye sọ̀rọ, yio si kọ́ ọ,
awọn ẹja inu okun yio si sọ fun ọ.
9 Tani kò mọ̀ ninu gbogbo wọnyi pe,
ọwọ Oluwa li o şe nkan yi?
10 Lọwọ ẹniti ẹmi ohun alãye gbogbo
gbé wà, ati ẹmi gbogbo araiye.
11 Eti ki idán ọ̀rọ wò bi? tabi adùn ẹnu
ki isi tọ onjẹ rẹ̀ wò?
12 Awọn arugbo li ọgbọ́n wà fun, ati
ninu gigùn ọjọ li oye.
13 Pẹlu rẹ̀ (Ọlọrun) li ọgbọ́n ati agbarà,
on ni ìmọ ati oye,
14 Kiyesi i, o biwó, a kò si le igbe ró
mọ́, o se enia mọ́, kò si sí işisilẹ̀ kan.
15 Kiyesi i, o da awọn omi duro, nwọn
si gbẹ, o si rán wọn jade, nwọn si şẹ bo
ilẹ aiye yipo.
16 Pẹlu rẹ̀ li agbara ati ọgbọ́n, ẹniti
nşìna ati ẹniti imu ni şìna tirẹ̀ ni nwọn işe.
17 O mu awọn igbimọ̀ lọ nihoho, a si sọ
awọn onidajọ di wère.
18 O tu ide ọba, a si fi àmure gbà wọn
li ọ̀ja.
19 O mu awọn alufa lọ nihoho, o si tẹ
ori awọn alagbara bá.
20 O mu ọ̀rọ-ẹnu ẹni-igbẹkẹle kuro, o si
ra awọn àgbàgbà ni iye.
21 O bù ẹ̀gan lu awọn ọmọ-alade, o si
tú àmure awọn alagbara.
22 O hudi ohun ti o sigbẹ jade lati inu
òkunkun wá, o si mu ojiji ikú jade wá sinu
imọlẹ.
23 On a mu orilẹ-ède bi si i, a si run
wọn, on a sọ orilẹ-ède di nla, a si tun şé
wọn kù.
24 On a gbà aiya olú awọn enia aiye, a
si ma mu wọn wọ́ kakiri ninu iju nibiti
ọ̀na kò si.
25 Nwọn a ma fi ọwọ ta ilẹ ninu òkun-
kun laisi imọlẹ, on a si ma mu wọn tàse
irin bi ọmuti.

## ORI 13.

WO o, oju mi ti ri gbogbo eyi ri, eti mi
si gbọ́ o si ti ye e.
2 Ohun ti ẹnyin mọ̀, emi mọ̀ pẹlu, emi
kì işe ọmọ-ẹhin nyin.
3 Nitotọ emi o ba Olodumare sọ̀rọ, emi
si nfẹ ba Ọlọrun sọ asọye.
4 Ẹnyin ni onihumọ eke, onişegun lasan
ni gbogbo nyin.
5 O şe! ẹ ba kuku pa ẹnu nyin mọ
patapata! eyini ni iba si şe ọgbọ́n nyin.

Digitized by Google

6 Ẹ gbọ́ awiye mi nisisiyi, ẹ si fetisilẹ
si aroye ẹnu mi.
7 Ẹnyin fẹ sọ isọkusọ fun Ọlọrun? ki
ẹ si fi ẹ̀tan sọ̀rọ gbè e?
8 Ẹnyin fẹ ṣojusaju rẹ̀, ẹnyin fẹ igbìjà
fun Ọlọrun?
9 O ha dara ti yio fi hudi nyin silẹ,
tabi ki ẹnyin tàn a bi ẹnikan ti itan
ẹnikeji.
10 Yio ma ba nyin wi nitotọ, bi ẹnyin
ba ṣojusaju enia nikọ̀kọ.
11 Iwa ọlá rẹ̀ ki yio bà nyin lẹ̃ru bi?
ipaiya rẹ̀ ki yio pá nyin laiya?
12 Iranti nyin dabi ẽru, ilu-odi nyin
dabi ilu-odi amọ̀.
13 Ẹ pa ẹnu nyin mọ kuro lara mi, ki
emi ki o le sọ̀rọ, ohun ti mbọ̀ wá iba mi,
ki o ma bọ̀.
14 Njẹ nitori kili emi ṣe nfi ehin mi
bù ẹran ara mi jẹ, ti mo si gbe ẹmi mi le
ara mi lọwọ?
15 Bi o tilẹ pa mi, sibẹ emi o ma gbẹ-
kẹle e, ṣugbọn emi o ma tẹnumọ ọ̀na mi
niwaju rẹ̀.
16 Eyi ni yio si ṣe igbàla mi pe: àga-
bagebe kì yio wá siwaju rẹ̀.
17 Ẹ gbọ́ ọ̀rọ ẹnu mi ni ifaiyabalẹ, ati
asọpe mi li eti nyin.
18 Wò o nisisiyi emi ti ladi ọ̀ran mi
silẹ; emi mọ̀ pe a o da mi lare.
19 Tani on ti yio ba mi ṣàroye? njẹ
nisisiyi, emi fẹ pa ẹnu mi mọ, emi o si
jọwọ ẹmi mi lọwọ.
20 Ṣugbọn ọkan ni, máṣe ṣe ohun meji
yi si mi, nigbana ni emi kì yio si fi ara mi
pamọ kuro fun ọ.
21 Fa ọwọ rẹ sẹhin kuro lara mi; má
si jẹ ki ẹ̀ru rẹ ki o pá mi laiya.
22 Nigbana ni ki iwọ ki o pè, emi o si
dahùn, tabi jẹ ki nma sọ̀rọ, ki iwọ ki o si
da mi lohùn.
23 Melo li aiṣedede ati ẹ̀ṣẹ mi, mu mi
mọ̀ irekọja ati ẹ̀ṣẹ mi!
24 Nitori kini iwọ ṣe pa oju rẹ mọ́, ti o
si yàn mi li ọta rẹ?
25 Iwọ o fa ewe ya ti afẹfẹ nfẹ sihin
sọhun: iwọ a si ma lepa akemọlẹ poroporo
gbigbẹ!
26 Nitoripe iwọ kọwe ohun kikoro si
mi, o si mu mi ni aiṣedede ewe mi.
27 Iwọ kàn àba mọ mi lẹsẹ pẹlu, iwọ si
nwò ipa ọ̀na irin mi li awofin, iwọ si nfi
ãlà yi gigisẹ mi ka.
28 Ani, yi ẹniti a ti run ka, bi ohun ti
o bu, bi aṣọ ti kòkoro jẹ bajẹ.

## ORI 14.

ENIA ti a bi ninu obirin ọlọjọ diẹ ni, o
si kún fun iponju.
2 O jade wá bi itana eweko, a si ke e
lulẹ, o si nfò lọ bi ojiji, kò si duro pẹ́.
3 Iwọ si nṣiju rẹ wò iru eyinì, iwọ si
mu mi wá sinu idajọ pẹlu rẹ.
4 Tali o le mu ohun mimọ́ lati inu aimọ́
jade wá? kò si ẹnikan!
5 Njẹ ati pinnu ọjọ rẹ̀, iye oṣu rẹ̀ mbẹ
li ọwọ rẹ, iwọ ti pàla rẹ̀, bẹ̃li on kò le
ikọja rẹ̀.
6 Yipada kuro lọdọ rẹ̀, ki o le simi titi
yio fi pé ọjọ rẹ̀ bi alagbaṣe.
7 Nitoripe abá wà fun igi, bi a ba ke e
lulẹ, pe yio si tun sọ, ati pe ẹka rẹ̀ titun,
kì yio dá.
8 Bi gbongbo rẹ̀ tilẹ di ogbó ninu ilẹ, ti
kukute rẹ̀ si kú ni ilẹ.
9 Sibẹ nigbati o ba gbõrùn omi, yio sọ,
yio si yọ ẹka jade bi eweko.
10 Ṣugbọn enia kú, a si ṣàn danu; ani
enia jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ, on ha da?
11 Bi omi ti itàn ninu ipa odò, ti odò si
ifà ti si igbẹ.
12 Bẹ̃li enia dubulẹ ti kò si dide mọ́,
titi ọrun kì yio fi si mọ́, nwọn kì yio ji, a
kì yio ji wọn kuro loju orun wọn.
13 A! iwọ iba fi mi pamọ ni ipo-okú, ki
iwọ ki o fi mi pamọ ni ìkọkọ, titi ibinu rẹ
yio fi rekọja, iwọ iba lana igba kan silẹ
fun mi, ki o si ranti mi.
14 Bi enia ba kú yio si tun yè bi? gbo-
gbo ọjọ igba ti a là silẹ fun mi li emi o
duro dè, titi amudọtun mi yio fi de.
15 Iwọ iba pè, emi iba si da ọ lohùn,
iwọ o si ni ifẹ si iṣẹ ọwọ rẹ.
16 Ṣugbọn nisisiyi iwọ nkaye iṣisẹ mi,
iwọ kò fà ọwọ rẹ kuro nitori ẹ̀ṣẹ mi.
17 A fi edidi di irekọja mi sinu àpo, iwọ
si rán aiṣedede mi pọ̀.
18 Ati nitotọ oke nla ti o ṣubu, o dasan,
a si ṣi apata kuro ni ipo rẹ̀.
19 Omi a ma yinrin okuta, iwọ a si mu
omi ṣàn bo ohun ti o hù jade lori ilẹ, iwọ
si sọ ireti enia di ofo.
20 Iwọ si ṣẹgun rẹ̀ lailai, on si kọja lọ,
iwọ pa awọ oju rẹ̀ dà, o si ran a lọ kuro.
21 Awọn ọmọ rẹ̀ bọ́ si ipo ọlá, on kò si
mọ̀, nwọn si rẹ̀ silẹ, on kò si kiyesi i lara
wọn.
22 Ṣugbọn ẹran-ara rẹ̀ ni yio ri irora,
ọkàn rẹ̀ ni yio si ma ni ibinujẹ ninu rẹ̀.

Digitized by Google

## ORI 15.

NIGBANA ni Elifasi, ara Tema, dahùn
wipe,
2 Ọlọgbọ́n a ma sọ̀rọ ìmọ asan, ki o si
ma fi afẹ́fẹ ila-õrùn kún ara rẹ̀ ninu:
3 On le ma fi aroye sọ̀rọ ti kò li ère,
tabi pẹlu ọ̀rọ ninu eyiti kò le fi ṣe rere?
4 Ani iwọ ṣa ìbẹru tì, iwọ si dí adura
lọna niwaju Ọlọrun.
5 Nitoripe ẹnu ara rẹ li o jẹwọ ẹ̀ṣẹ rẹ,
iwọ si yàn ahọn alarekereke li ãyò.
6 Ẹnu ara rẹ li o da ọ lẹbi, kì iṣe emi,
ani ète ara rẹ li o jẹri tì ọ.
7 Iwọ́ ha iṣe ọkọnrin ti a kọ́ bi? tabi a
ha dá ọ ṣaju awọn oke?
8 Iwọ gburo aṣiri Ọlọrun ri, tabi iwọ ha
dá ọgbọ́n duro sọdọ ara rẹ?
9 Kini iwọ mọ̀ ti awa kò mọ̀, oye kili o
ye ọ ti kò si ninu wa.
10 Elewú ogbó ati ògbologbo enia wà
pẹlu wa, ti nwọn gbó jù baba rẹ lọ.
11 Itunu Ọlọrun ha kere lọdọ rẹ, ọ̀rọ
kan si ṣe jẹjẹ jù lọdọ rẹ.
12 Ẽṣe ti aiya rẹ fi ndà ọ kiri, tabi kini
iwọ tẹjumọ wofin.
13 Ti iwọ fi yi ẹmi rẹ pada lodi si Ọlọ-
run, ti o fi njẹ ki ọ̀rọkọrọ ki o ma bọ li ẹnu
rẹ bẽ?
14 Kili enia ti o fi mọ́? ati ẹniti a tinu
obirin bi ti yio fi ṣe olododo?
15 Kiyesi i, on (Ọlọrun) kò gbẹkẹle awọn
ẹni-mimọ́ rẹ̀, ani awọn ọrun kò mọ́ li oju
rẹ̀.
16 Ambọtori enia, ẹni irira ati elẽri, ti
nmu ẹ̀ṣẹ bi ẹni mu omi.
17 Emi o fi hàn ọ, gbọ́ ti emi, eyi ti emi
si ri, on li emi o si sọ.
18 Ti awọn ọlọgbọ́n ti pa ni ìtan lati
ọdọ awọn baba wọn wá, ti nwọn kò si fi
pamọ́.
19 Awọn ti a fi ilẹ aiye fun nikan, alejo
kan kò si là wọn kọja.
20 Enia buburu nṣe lãlã, pẹlu irora li
ọjọ rẹ̀ gbogbo, ati iye ọdun li a dá silẹ fun
aninilara.
21 Iró ìbẹru mbẹ li eti rẹ̀, ninu irora ni
alaparun a dide si i.
22 O kò gbagbọ pe on o jade kuro ninu
okunkun; a si ṣa a sapakan fun idà.
23 O nwò kakiri fun onjẹ, wipe, nibo li
o wà, o mọ̀ pe ọjọ òkunkun sunmọ tosi.
24 Ipọnju pẹlu irora ọkàn yio mu u bẹ̀ru,
nwọn o si ṣẹgun rẹ̀ bi ọba ti imura ogun.
25 Nitoripe o ti nawọ rẹ̀ jade lodi si
Ọlọrun, o si imura rẹ̀ le lodi si Olodumare.
26 O sure, o si fi ẹhin giga kọlu u, ani
fi ike-koko apata rẹ̀ ti o nipọn.
27 Nitoriti on fi ọra rẹ̀ bo ara rẹ̀ loju, o
si ṣe jabajába ọra si ẹgbẹ rẹ̀.
28 On si gbe inu ahoro ilu itakétẹ́, ati
ninu ileyile ti enia kò gbe mọ́, ti o mura
tan lati di àlapa.
29 On kò le ilà, bẽni ohun ini rẹ̀ kò le
iduro pẹ, bẽni kò le imu pipé rẹ̀ duro pẹ
lori aiye.
30 On kì yio jade kuro ninu okunkun,
ọ̀wọ-iná ni yio jo ẹká rẹ̀, ati nipasẹ ẹmi ẹnu
rẹ̀ ni yio ma kọja lọ kuro.
31 Ki on ki o má ṣe gbẹkẹle asan, o tan
ara rẹ̀ jẹ; nitoripe asan ni yio jasi ère rẹ̀.
32 A o mu u ṣẹ ṣaju pipe ọjọ rẹ̀, ẹka rẹ̀
kì yio si tutu.
33 Yio si gbọ̀n talubọ eso rẹ̀ dànu bi
àjara, yio si rẹ̀ itana rẹ̀ nù bi ti igi olifi.
34 Nitoripe ajọ awọn àgabagebe yio tuka,
iná ni yio si jo agọ abẹtẹlẹ.
35 Nwọn loyun ìwa-ika, nwọn si bi ẹ̀ṣẹ,
ikùn wọn si pèse ẹ̀tan.

## ORI 16.

NIGBANA ni Jobu dahùn o si wipe,
2 Emi ti gbọ́ iru ohun pipọ bẽ ri;
ayọnilẹnu onitunu enia ni gbogbo nyin.
3 Ọ̀rọ asan lè ni opin? tabi kili o gbó ọ
laiya ti iwọ fi dahùn.
4 Emi pẹlu le isọ bi ẹnyin, bi ọkàn nyin
ba wà ni ipó ọkàn mi, emi le iko ọ̀rọ pọ̀ si
nyin li ọrùn, emi a si mì ori mi si nyin.
5 Emi iba fi ọ̀rọ ẹnu mi gbà nyin ni
iyanju, ati ṣiṣi ète mi iba si tu ibinujẹ nyin.
6 Bi emi tilẹ sọ̀rọ ibinujẹ mi kò tù; bi
mo si tilẹ dakẹ, nibo li itunu mi de?
7 Ṣugbọn nisisiyi, o da mi lagara, iwọ
(Ọlọrun) mu gbogbo ẹgbẹ mi takete.
8 Iwọ si fi ikiweje kún mi lara, ti o jẹri
tì mi; ati rirù ti o yọ lara mi, o jẹri tì mi
li oju.
9 Ibinu rẹ̀ li o fà mi ya, o si ṣọta mi; o
pa ehin rẹ̀ keke si mi, ọta mi si gboju rẹ̀ si
mi.
10 Nwọn ti fi ẹnu wọn yán si mi, nwọn
gbá mi li ẹrẹkẹ ni igbá ẹ̀gan, nwọn kó ara
wọn jọ pọ̀ si mi.
11 Ọlọrun ti fi mi le ọwọ ẹni-buburu, o
si mu mi ṣubu si ọwọ enia ẹlẹ̀ṣẹ.
12 Mo ti joko jẹ, ṣugbọn o fa mi já o si
dì mi li ọrùn mu, o si gbọ̀n mi tutu, o si
gbe mi kalẹ ṣe àmi itasi rẹ̀.
13 Awọn tafatafa rẹ̀ duro yi mi kakiri;
o là mi laiya pẹ̀rẹ, kò si dasi, o si tú orõrò
ara mi dà silẹ.

Digitized by Google

14 Ibajẹ lori ibajẹ li o fi ba mi jẹ; o
sure kọlù mi bi òmirán.
15 Mo rán aṣọ-apo bò ara mi, mo si rẹ̀
iwo mi silẹ ninu erupẹ.
16 Oju mi ti pọ́n fun ẹkún, ojiji ikú si
ṣẹ si ipenpeju mi.
17 Kì iṣe nitori aiṣotitọ kan li ọwọ mi,
adura mi si mọ́ pẹlu.
18 A! ilẹ aiye, iwọ máṣe bò ẹ̀jẹ mi, ki
ẹkún mi máṣe ni ipò kan.
19 Njẹ nisisiyi kiyesi i! ẹlẹri mi mbẹ li
ọrun, ẹ̀ri mi si mbẹ loke ọrun.
20 Awọn ọrẹ mi nfi mi ṣẹ̀sin, ṣugbọn oju
mi ndà omije sọdọ Ọlọrun.
21 Ibaṣepe ẹnikan le ma ṣe alagbawi fun
ẹnikeji lọdọ Ọlọrun, bi enia kan ti iṣe
alagbawi fun ẹnikeji rẹ̀.
22 Nitori nigbati iye ọdun diẹ rekọja
tan, nigbana ni emi o lọ si ibi ti emi kì yio
pada bọ̀.

## ORI 17.

EMI mi bajẹ, ọjọ mi parun, isa-okú duro
dè mi.
2 Nitõtọ! awọn ẹlẹya wà lọdọ mi, oju
mi si tẹmọ́ imunibinu wọn.
3 Njẹ nisisiyi, fi lelẹ! yàn onigbọwọ
fun mi lọdọ rẹ; tani oluwa rẹ̀ ti yio ba mi
so ọwọ lù?
4 Nitoripe iwọ ti se wọn laiya kuro ninu
oye, nitorina iwọ kì yio gbé wọn leke.
5 Ẹniti o fi awọn ọrẹ hàn fun igára, on
ni oju awọn ọmọ rẹ̀ yio mu ofo.
6 O si sọ mi di ẹni-owe fun awọn enia,
niwaju wọn ni mo dabi ẹni itutọ́ si li oju.
7 Oju mi ṣú baibai pẹlu nitori ibinujẹ,
gbogbo ẹ̀ya ara mi si dabi ojiji.
8 Awọn olododo yio yanu si eyi, ẹni
alaiṣẹ̀ si binu si awọn àgabagebe.
9 Olododo pẹlu yio di ọ̀na rẹ̀ mu, ati
ọlọwọ mimọ́ yio ma lera siwaju.
10 Ṣugbọn bi o ṣe ti gbogbo nyin, ẹ yi-
pada, ki ẹ si tun bọ̀ nisisiyi, emi kò le ri
ọlọgbọ́n kan ninu nyin.
11 Ọjọ ti emi ti kọja, ìro mi ti fà já, ani
iro inu mi.
12 A sọ oru di ọ̀san; nwọn ni, imọlẹ
summọ ibiti òkunkun de.
13 Bi mo tilẹ ni ireti, ipo-okú ni ile mi,
mo ti tẹ́ bùsun mi sinu òkunkun.
14 Emi ti wi fun idibajẹ pe, Iwọ ni baba
mi, ati fun kòkoro pe, Iwọ ni iya mi ati
arabirin mi.
15 Ireti mi ha dà nisisiyi? bi o ṣe ti
ireti mi ni, tani yio ri i?
16 O sọkalẹ lọ sinu ọgbun ipo-okú, ni-
gbati a jumọ simi pọ̀ ninu erupẹ ilẹ.

## ORI 18.

NIGBANA ni Bildadi, ara Ṣua, dahùn o
si wipe,
2 Nigba wo li ẹnyin o to fi idi ọ̀rọ tì; ẹ
rò o, nigbẹhin rẹ̀ li awa o to ma sọ.
3 Nitori kili a ṣe nkà wa si bi ẹranko, ti
a si nkà wa si bi ẹni ẹ̀gan li oju nyin!
4 Iwọ nfa ara rẹ ya pẹrẹpẹrẹ ninu ibinu
rẹ, ki a ha kọ̀ aiye silẹ nitori rẹ bi? tabi ki
a ṣi apata kuro ni ipo rẹ̀?
5 Nitotọ imọlẹ enia buburu li a o pa
kuro, ọ̀wọ-iná rẹ̀ kì yio si tan imọlẹ:
6 Imọlẹ yio ṣokunkun ninu agọ rẹ̀, fitila
rẹ̀ li a o si pa pẹlu rẹ̀.
7 Irin ẹsẹ agbara rẹ̀ yio di fifọn, ìmọ on
tikararẹ ni yio bi i ṣubu.
8 Nipa ẹsẹ ontikararẹ̀ o ti bọ́ sinu àwọn,
o si rìn lori okùn didẹ.
9 Okùn ẹgẹ́ ni yio mu u ni gigìsẹ, awọn
igara yio si ṣẹgun rẹ̀.
10 A dẹkùn silẹ fun u lori ilẹ, a si wà
ọ̀fin fun u loju ọ̀na.
11 Ẹ̀ru nla yio bà a ni iha gbogbo, yio si
le e de ẹsẹ rẹ̀.
12 Ailera rẹ̀ yio di pipa fun ebi, iparun
yio dide duro si i ni iha rẹ̀.
13 Yio jẹ ẹ̀ya ara rẹ̀, akọbi ikú ni yio jẹ
agbara rẹ̀ run.
14 Eyi ti o fi gbẹkẹle ni a o fàtu kuro
ninu agọ rẹ̀, yio si tọ̀ ọba ẹ̀ru nla nì lọ.
15 Yio si ma joko ninu agọ rẹ̀ eyi ti kì
iṣe tirẹ̀, imi-õrùn li a o fún kakiri si ara ile
rẹ̀.
16 Gbongbo rẹ̀ yio gbẹ nisalẹ, a o si ke
ẹ̀ka rẹ̀ kuro loke.
17 Iranti rẹ̀ yio parun kuro li aiye, kì
yio si orukọ rẹ̀ ni igboro ilu.
18 A o si le e lati inu imọlẹ sinu òkun-
kun, a o si le e kuro li aiye.
19 Kì yio ni ọmọ bibi-kọnrin tabi ajọbi-
kọnrin ninu awọn enia rẹ̀, bẹ̃ni kò si ẹnikan
ti o kù ninu agbo ile rẹ̀.
20 Ẹnu yio ya awọn iran ti ìwọ-õrùn si
igba ọjọ rẹ̀, gẹgẹ bi ẹ̀ru iwarìri ti ba awọn
iran ti ila-õrùn.
21 Nitõtọ iru-bẹ̃ ni ibujoko awọn enia
buburu, eyi si ni ipo ẹni ti kò mọ̀ Ọlọrun.

## ORI 19.

NIGBANA ni Jobu dahùn o si wipe,
2 Yio ti pẹ to ti ẹnyin o fi ma bà mi
ninu jẹ, ti ẹnyin o fi ma fi ọ̀rọ kun mi ni
ìjanja?

Digitized by Google

3 Igba mẹwa li ẹnyin ti ngàn mi, oju kò
tì nyin ti ẹ fi jẹ mi niya.
4 Ki a fi si bẽ pe, mo ṣìna nitõtọ, ìṣina
mi wà lara emi tikarami.
5 Bi o tilẹ ṣepe ẹnyin o ṣogo si mi lori
nitõtọ, ti ẹ o si ma fi ẹ̀gan mi gun mi
loju.
6 Ki ẹ mọ̀ nisisiyi pe: Ọlọrun li o bì mi
ṣubu, o si nà àwọn rẹ̀ yi mi ka.
7 Kiyesi i, emi nkigbe pe, Ọwọ́ ala-
gbara! ṣugbọn a kò gbọ́ ti emi; mo kigbe
soke, bẽni kò si idajọ.
8 O sọ̀gba di ọ̀na mi ti emi kò le kọja, o
si mu òkunkun ṣú si ipa ọ̀na mi:
9 O ti bọ́ ogo mi, o si ṣi ade kuro li ori
mi.
10 O ti bà mi jẹ ni iha gbogbo, ẹmi si
pin; ireti mi li a o si fatu bi igi:
11 O si tinabọ ibinu rẹ̀ si mi, o si kà mi
si bi ọkan ninu awọn ọta rẹ̀.
12 Ẹgbẹ́ ogun rẹ̀ si dàpọ si mi, nwọn si
tẹgun si mi, nwọn si dó yi agọ mi ka.
13 O mu awọn arakọnrin mi jina si mi
rére, ati awọn ojulumọ mi di ajeji si mi
nitõtọ.
14 Awọn ajọbi mi fà sẹhin, awọn afara-
mọ́ ọrẹ mi si di onigbagbe mi.
15 Awọn ara inu ile mi ati awọn ọmọ-
birin iranṣẹ mi kà mi si ajeji, emi jasi ajeji
enia li oju wọn.
16 Mo pè iranṣẹ mi, on kò si da mi
lohùn, mo fi ẹnu mi bẹ̀ ẹ.
17 Ẹmi mi sú aya mi, ati õrùn mi sú
awọn ọmọ inu iya mi.
18 Ani awọn ọmọde fi mi ṣẹsin: mo dide,
nwọn si sọ̀rọ ẹ̀gan si mi.
19 Gbogbo awọn ọrẹ idimọpọ mi korira
mi, awọn olufẹ mi si kẹhinda mi.
20 Egungun mi lẹ mọ́ awọ ara mi ati
mọ́ ẹran ara mi, mo si bọ́ pẹlu awọ ehin
mi.
21 Ẹ ṣãnu fun mi, ẹ ṣãnu fun mi, ẹnyin
ọrẹ mi, nitori ọwọ Ọlọrun ti bà mi.
22 Nitori kili ẹnyin ṣe lepa mi bi Ọlọ-
run, ti ẹran ara mi kò tẹ́ nyin lọrùn!
23 A! Ibaṣepe a le kọwe ọ̀rọ mi nisisi-
yi, ibaṣepe a le dà a sinu iwe!
24 Ki a fi kalamu irin ati ti ojé kọ wọn
sinu apata fun lailai.
25 Ati emi, emi mọ̀ pe Oludande mi
mbẹ li ãyè, ati pe on bi Ẹni-ikẹhin ni yio
dide soke lori erupẹ ilẹ.
26 Ati lẹhin igba awọ ara mi, ti a ti ke
e kuro bi iru eyi, ati laili ẹran ara mi li
emi o ri Ọlọrun.
27 Ẹniti emi o ri fun ara mi, ti oju mi o
si wò, kì si iṣe ti ẹlomiran; ọkàn mi si
dáku ni inu mi.
28 Bi ẹnyin ba wipe, Awa o ti lepa rẹ̀
to! ati pe, gbongbo ọ̀rọ na li a sa ri li ọwọ
mi,
29 Ki ẹnyin ki o bẹ̀ru idà; nitoripe
ibinu ni imu ijiya idà wá: ki ẹnyin ki o lè
imọ̀ pe idajọ kan mbẹ.

## ORI 20.

NIGBANA ni Sofari, ara Naama, dahùn
o si wipe,
2 Nitorina ni ìro inu mi da mi lohùn,
ati nitori eyi na ni mo si yara si gidigidi.
3 Mo ti gbọ́ ẹsan ẹ̀gan mi, ẹmi oye mi si
da mi lohùn.
4 Iwọ kò mọ̀ eyi ri ni igba atijọ, lati
igba ti a sọ enia lọ̀jọ̀ silẹ aiye?
5 Pe, orin ayọ̀ enia buburu igba kukuru
ni, ati pe, ni iṣẹju kan li ayọ̀ àgabagebe.
6 Bi ọlanla rẹ̀ tilẹ goke de ọrun, ti ori
rẹ̀ si kan awọsamna.
7 Ṣugbọn yio ṣegbe lailai bi igbẹ́ ara rẹ̀;
awọn ti o ti ri i rí, yio wipe, On ha dà?
8 Yio fò lọ bi alá, a kì yio si ri i, ani a
o lé e lọ bi iran oru.
9 Oju ti o ti ri i rí pẹlu, kì yio si ri i
mọ́, bẽni ibujoko rẹ̀ kì yio si ri i mọ́.
10 Awọn ọmọ rẹ̀ yio ma wá ati ri oju-
rere lọdọ talaka, ọwọ rẹ̀ yio si kó ẹrù wọn
pada.
11 Egungun rẹ̀ kún fun agbara igba ewe
rẹ̀, ti yio ba a dubulẹ ninu erupẹ.
12 Bi ìwa buburu tilẹ dùn li ẹnu rẹ̀, bi
o tilẹ pa a mọ́ nisalẹ ahọn rẹ̀.
13 Bi o tilẹ dá a si, ti kò si kọ̀ ọ silẹ, ti
o pa a mọ sibẹ li ẹnu rẹ̀,
14 Ṣugbọn onjẹ rẹ̀ ninu ikùn rẹ̀ ti yipa-
da, o jasi orõro pamọlẹ ninu rẹ̀;
15 O ti gbe ọrọ̀ mì, yio si tun bì i jade,
Ọlọrun yio pọ̀ ọ yọ jade lati inu rẹ̀ wá.
16 O ti fà oró pamọlẹ mu, ahọn gunte
ni yio pa a.
17 Kì yio ri odò wọnni, iṣan omi, odò
ṣiṣàn oyin ati ti ori amọ́.
18 Ohun ti o ṣíṣẹ fun ni yio mu u pada,
kì yio si gbe e mì; gẹgẹ bi ọrọ̀ ti o ni, kì
yio si yọ̀ ninu rẹ̀.
19 Nitoriti o ninilara, o si ti kẹhinda
talaka, nitoriti o fi agbara gbe ile ti on kò
kọ́.
20 Nitori on kò mọ̀ iwa-pẹlẹ ninu ara
rẹ̀, ki yio si gbà ninu eyiti ọkàn rẹ̀ fẹ silẹ.
21 Ohun kan kò kù fun jijẹ rẹ̀, nitorina
ọrọ̀ rẹ̀ kì yio duro pẹ́.
22 Ninu titó ìkún rẹ̀ yio wà ninu ihale,

Digitized by Google

ọwọ gbogbo awọn oniyọnu ni yio dide si i
lori.
23 Yio si ṣe pe, nigbati o ma fi kún inu
rẹ̀ yo nì, Ọlọrun yio fa riru ibunu rẹ̀ si i
lori, nigbati o ba njẹun lọwọ.
24 Yio sá kuro lọwọ ohun-ogun irin,
ọrun akọ-irin ni yio ta a po yọ.
25 O fà a yọ, o si jade kuro lara, ani idà
didan ni njade lati inu orõro wá: ẹ̀ru-nla
mbẹ li ara rẹ̀.
26 Okunkun gbogbo ni a ti pamọ́ fun
iṣura rẹ̀, iná ti a kò fẹ́ ni yio jo o run: yio
si jẹ eyi ti o kù ninu agọ rẹ̀ run.
27 Ọrun yio fi ẹ̀ṣẹ rẹ̀ hàn, aiye yio si
dide duro si i.
28 Ibisi ile rẹ̀ yio kọja lọ, ati ohun ini
rẹ̀ yio ṣàn danu lọ li ọjọ ibinu Ọlọrun.
29 Eyi ni ipin enia buburu lati ọdọ
Ọlọrun wá, ati ogún ti a yàn silẹ fun u lati
ọdọ Oluwa wá.

## ORI 21.

SUGBỌN Jobu dahùn, o si wipe,
2 Ẹ tẹti silẹ dẹdẹ si ohùn mi, ki eyi
ki o jasi itunu nyin.
3 Ẹ jọwọ mi ki emi sọ̀rọ, lẹhin igbati
mo ba sọ tan, iwọ ma fi ṣẹsin nṣo.
4 Bi o ṣe ti emi ni, aroye mi iṣe si enia
bi, tabi ẽtiṣe ti ọkàn mi kì yio fi ṣe aibalẹ?
5 Ẹ wò mi fin, ki ẹnu ki o si yà nyin, ki
ẹ si fi ọwọ le ẹnu nyin.
6 Ani nigbati mo ranti, ẹ̀ru bà mi,
iwarìri si mu mi lara.
7 Nitori kini enia buburu fi wà li ãyè,
ti nwọn gbó, ani ti nwọn di alagbara ni
ipa?
8 Iru-ọmọ wọn fi idi kalẹ li oju wọn pẹlu
wọn, ati ọmọ-ọmọ wọn li oju wọn.
9 Ile wọn wà laini ewu, bẹ̃ni ọpa-ìna
Ọlọrun kò si lara wọn.
10 Akọ-malu wọn a ma gùn, kì isi isé,
abomalu wọn a ma bi, ki isi iṣẹnu;
11 Nwọn a ma rán awọn ọmọ wọn wẹwẹ
jade bi agbo ẹran, awọn ọmọ wọn a si ma
jó.
12 Nwọn mu ohun ọnà orin timbreli ati
dùru, nwọn si nyọ̀ si ohùn ifère.
13 Nwọn lo ọjọ wọn ninu ọrọ̀; ni iṣẹju-
kan nwọn a lọ si ipo-okú.
14 Nitorina ni nwọn ṣe wi fun Ọlọrun
pe, Lọ kuro lọdọ wa, nitoripe awa kò fẹ
ìmọ ipa ọ̀na rẹ!
15 Kini Olodumare ti awa o fi ma sin i!
ere kili a o si jẹ bi awa ba gbadura si i!
16 Kiyesi i, alafia wọn kò si nipa ọwọ
wọn, ìmọ enia buburu jina si mi réré.
17 Igba melomelo ni a npa fitila enia
buburu kú? igba melomelo ni iparun wọn
de ba wọn, ti Ọlọrun isi ma pin ibinujẹ
ninu ibinu rẹ̀.
18 Nwọn dabi akekun oko niwaju afẹfẹ,
ati bi iyangbo, ti ẹfufu-nla fẹ lọ.
19 Ọlọrun to ìya-ẹ̀ṣẹ rẹ̀ jọ fun awọn ọmọ
rẹ̀, o san a fun u, yio si mọ̀ ọ.
20 Oju rẹ̀ yio ri iparun ara rẹ̀, yio si ma
mu ninu riru ibinu Olodumare.
21 Nitoripe alafia kili o ni ninu ile rẹ̀
lẹhin rẹ̀, nigbati a ba ke iye oṣù rẹ̀ kuro li
agbedemeji?
22 Ẹnikẹni le ikọ́ Ọlọrun ni ìmọ? on ni
sa nṣe idajọ ibi giga.
23 Ẹnikan a kú ninu pipé agbara rẹ̀, ti o
wà ninu irọra ati idakẹ patapata.
24 Ọpọ́n rẹ̀ kún fun omi-ọmú, egungun
rẹ̀ si tutu fun ọra.
25 Ẹlomiran a si kú ninu kikoro ọkàn
rẹ̀, ti kò si fi inu didun jẹun.
26 Nwọn o dubulẹ bakanna ninu erupẹ,
kòkoro yio si ṣùbo wọn.
27 Kiyesi i, emi mọ̀ iro inu nyin ati
arekereke ti ẹnyin fi gba dulumọ si mi.
28 Nitoriti ẹnyin wipe, nibo ni ile awọn
ọmọ alade, ati nibo ni agọ awọn enia bu-
buru nì gbe wà?
29 Ẹnyin kò bere lọwọ awọn ti nkọja lọ
li ọ̀na, ẹnyin kò mọ̀ àmi wọn? pe,
30 Enia buburu ni a fi pamọ fun ọjọ
iparun, a o si mu wọn jade li ọjọ riru
ibinu.
31 Tani yio sọ ipa-ọ̀na rẹ̀ kò o li oju,
tani yio si san pada fun u li eyi ti o ti ṣe?
32 Sibẹ a o si sin i li ọ̀na ipo-okú, yio si
ma ṣọ́ orori okú.
33 Ogulutu ọfin yio dùn mọ ọ, gbogbo
enia yio si ma tọ̀ ọ lẹhin, bi enia ainiye ti
lọ ṣiwaju rẹ̀.
34 E ha ti ṣe ti ẹnyin fi ntù mi ninu
lasan! bi o ṣepe ni idahùn nyin eké kù
nibẹ.

## ORI 22.

NIGBANA ni Elifasi, ara Tema, dahùn
wipe,
2 Enia le iṣe rere fun Ọlọrun, bi ọlọgbọ́n
ti iṣe rere fun ara rẹ̀.
3 Ohun ayọ̀ ha ni fun Olodumare pe,
olododo ni iwọ? tabi ere ni fun u, ti iwọ
mu ọ̀na rẹ pé?
4 Yio ha ba ọ wi bi nitori ìbẹru Ọlọrun
rẹ, yio ha ba ọ lọ sinu idajọ bi?
5 Iwa-buburu rẹ kò ha tobi, ati ẹ̀ṣẹ rẹ
lainiye?

Digitized by Google

6 Nitõtọ iwọ gbà ohun ẹri li ọwọ arakọnrin rẹ lainidi, iwọ si tú onihoho li aṣọ wọn.
7 Iwọ kò fi omi fun alãrẹ mu, iwọ si hawọ onjẹ fun ẹniti ebi npa.
8 Bi o ṣe ti alagbara nì ni, on li o ni aiye, ọlọla si tẹdo sinu rẹ̀.
9 Iwọ ti rán awọn opó pada lọ li ọwọ ofo, apa awọn ọmọ alainibaba ti di ṣiṣẹ́.
10 Nitorina ni idẹkun ṣe yi ọ kakiri, ati ìbẹru ojiji nyọ ọ lẹnu.
11 Tabi iwọ kò ha ri okunkun, ati ọ̀pọlọpọ omi ti o bò ọ mọlẹ?
12 Ọlọrun kò ha jẹ Ẹni giga ọrun? sa wò ori awọn ìrawọ̀ bi nwọn ti ga tó!
13 Iwọ si wipe, Ọlọrun ti ṣe mọ̀, on ha le iṣe idajọ lati inu awọsanma dudu wá bi?
14 Awọsanma ti o nipọn ni ibora fun u, ti kò fi le riran; o si rin ninu ayika ọrun.
15 Iwọ fẹ rìn ipa-ọ̀na igbani ti awọn enia buburu ti rìn.
16 Ti a ke lulẹ kuro ninu aiye laipé ọjọ wọn, ipilẹ wọn ti de bi odò ṣiṣàn.
17 Awọn ẹniti o wi fun Ọlọrun pe, Lọ kuro lọdọ wa! kili Olodumare yio ṣe fun wọn.
18 Sibẹ o fi ohun rere kún ile wọn! ṣugbọn ìmọ enia-buburu jìna si mi!
19 Awọn olododo ri i, nwọn si yọ̀, awọn alailẹ̀ṣe si fi wọn rẹrin ẹlẹya pe:
20 Lotitọ awọn ọta wa ni a ke kuro, iná yio si jó iyokù wọn run.
21 Fa ara rẹ sunmọ Ọlọrun, iwọ o si ri alafia; nipa eyinì rere yio wá ba ọ.
22 Emi bẹ̀ ọ, gba ofin lati ẹnu rẹ̀ wá, ki o si tò ọ̀rọ rẹ̀ si aiya rẹ.
23 Bi iwọ ba yipada sọdọ Olodumare, a si gbe ọ ró, bi iwọ ba si mu ẹ̀ṣẹ jina rére kuro ninu agọ rẹ.
24 Ti iwọ ba tẹ wura daradara silẹ lori erupẹ ati wura ofiri labẹ okuta odò.
25 Nigbana ni Olodumare yio jẹ iṣura rẹ, ani yio si jẹ fadaka fun ọ ni ọ̀pọlọpọ.
26 Lotitọ nigbana ni iwọ o ni inu didùn ninu Olodumare, iwọ o si gbe oju rẹ soke sọdọ Ọlọrun.
27 Bi iwọ ba gbadura rẹ sọdọ rẹ̀, yio si gbọ́ tirẹ, iwọ o si san ẹ̀jẹ́ rẹ.
28 Iwọ si gbimọ ohun kan pẹlu, yio si fi idi mulẹ fun ọ; imọlẹ yio si mọ́ sipa ọ̀na rẹ.
29 Nigbati ipa-ọ̀na rẹ ba lọ sisalẹ, nigbana ni iwọ o wipe, Igbesoke mbẹ! Ọlọrun yio si gba onirẹlẹ là!
30 Yio gba ẹniti kì iṣe alaijẹbi là, a o si gbà a nipa mimọ́ ọwọ rẹ.

## ORI 23.

NIGBANA ni Jobu si dahùn wipe,
2 Ani loni ni ọ̀ran mi korò; ọwọ mi si wuwo si ikerora mi.
3 A! emi iba mọ̀ ibi ti emi iba wá Ọlọrun ri! ki emi ki o tọ̀ ọ lọ si ibujoko rẹ̀,
4 Emi iba si tò ọran na niwaju rẹ̀, ẹnu mi iba si kún fun aroye.
5 Emi iba si mọ̀ ọ̀rọ ti on iba fi da mi lohùn, oye ohun ti iba wi a si ye mi.
6 Yio ha fi agbara nla ba mi wijọ bi? agbẹ́dọ̀! kiki on o si kiyesi mi:
7 Nibẹ li olododo le iba a wijọ, bẽli emi o si bọ́ li ọwọ onidajọ mi lailai.
8 Si wò! bi emi ba lọ si iha ila-õrùn, on kò si nibẹ, ati si iwọ-õrùn ni, emi kò si roye rẹ̀:
9 Niha ariwa bi o ba ṣiṣẹ nibẹ, emi kò ri i, o fi ara rẹ̀ pamọ niha gusu, ti emi kò le iri i.
10 Ṣugbọn on mọ̀ ọ̀na ti emi ntọ̀, nigbati o ba dan mi wò, emi o jade bi wura.
11 Ẹsẹ mi ti tẹle ipasẹ irin rẹ̀, ọ̀na rẹ̀ ni mo ti kiyesi, ti nkò si yà kuro.
12 Bẽni emi kò pada sẹhin kuro ninu ofin ẹnu rẹ̀, emi si pa ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ mọ́ jù ofin inu mi lọ.
13 Ṣugbọn oninukan li on, tani yio si yi i pada? Eyiti ọkàn rẹ̀ si ti fẹ, eyi na ni iṣe.
14 Nitõtọ ohun ti ati yàn silẹ fun mi ni nṣe, ọ̀pọlọpọ iru bẹ li o wà li ọwọ rẹ̀.
15 Nitorina ni ara ko ṣe rọ̀ mi niwaju rẹ̀, nigbati mo ba rò o, ẹ̀ru a ba mi.
16 Nitoripe Ọlọrun ti pá mi li aiya, Olodumare si ndamu mi.
17 Nitoriti a kò ti ke mi kuro niwaju òkunkun, bẽni kò pa òkùnkùn-biribiri mọ kuro niwaju mi.

## ORI 24.

ẼṢE bi igba-igba kò pamọ lọdọ Olodumare; ti awọn ojulumọ rẹ̀ kò ri ọjọ rẹ̀?
2 Nwọn a ṣi àmi àla ilẹ, nwọn a fi agbara ko agbo ẹran lọ, nwọn si bọ́ wọn.
3 Nwọn a si dà kẹtẹkẹtẹ alainibaba lọ, nwọn a si gba ọdá-malu opó li ohun ògo.
4 Nwọn a bì alaini kuro loju ọ̀na, awọn talaka aiye a sa pamọ́ pọ̀.
5 Kiyesi i, bi kẹtẹkẹtẹ igbẹ ninu ijù ni nwọn ijade lọ si iṣẹ wọn; nwọn a tete dide lati wá ohun ọdẹ; ijù pese onjẹ fun wọn ati fun awọn ọmọ wọn.
6 Olukuluku a si ṣa ọka onjẹ-ẹran rẹ̀

Digitized by Google

oko, nwọn a si ká ọgba-ajara enia
ru.
Nihoho ni nwọn ma sùn laini aṣọ, ti
kò ni ibora ninu otutu.
Ọwara ojo oke-nla si pa wọn, nwọn si
apata nitoriti kò si abo.
Nwọn ja ọmọ-alainibaba kuro li ẹnu-
nwọn si gbà ohun ẹ̀ri li ọwọ talaka.
Nwọn rìn kiri nihoho laili aṣọ, awọn
i npa rẹrù ìdi-ọka.
Awọn ẹniti nfún ororo ninu agbala
ti nwọn si ntẹ ifunti àjara, ongbẹ si
wọn.
Awọn enia nkerora lati ilu wá, ọkàn
ẹniti o gbọgbẹ kigbe soke; sibẹ
un kò kiyesi wère na.
Awọn li o wà ninu awọn ti o kọ̀
ẹ, nwọn kò mọ̀ ipa ọ̀na rẹ̀, bẹni nwọn
uro nipa ọ̀na rẹ̀.
Panipani a dide li afemọ́jumọ pa ta-
ati alaini, ati li oru a di olè.
Oju àlagbere pẹlu duro de ofefe ọjọ, o
Oju ẹnikan kì yio ri mi, o si fi iboju
rẹ̀.
Li òkunkun nwọn a runlẹ wọle, ti
n ti fi oju sọ fun ara wọn li ọsan, nwọn
nọ̀ imọlẹ.
7 Nitoripe bi oru dudu ni owurọ̀ fun
gbo wọn; nitoriti nwọn si mọ̀ ibẹru oru
u.
8 O yara lọ bi ẹni loju omi; ifibu ni
wọn li aiye, on kò rìn lọ mọ li ọ̀na
a-ajara.
9 Ọdá ati õru ni imu omi ojo-didi gbẹ,
i isa-okú irun awọn ẹ̀lẹṣẹ.
0 Inu ibímọ yio gbagbe rẹ̀, kokoro ni
ma fi adun jẹun lara rẹ̀, a kì yio ranti
nọ́; bẹ̃ni a o si ṣẹ ìwa-buburu bi ẹni ṣẹ

1 Ẹniti o hù ìwa-buburu si agàn ti kò
i, ti kò ṣe rere si opó.
2 O fi ipá rẹ̀ fà alagbara lọ pẹlu; o
e, kò si ẹniti ẹmi rẹ̀ da loju.
3 On si fi ìwa ailewu fun u, ati ninu eyi
a o si tì i lẹhin, oju rẹ̀ si wà ni ipa-ọna
n.
24 A gbe wọn lekè nigba diẹ, nwọn kọja
a si rẹ̀ wọn silẹ, a si mu wọn kuro li
, bi awọn ẹlọmiran, a si ke wọn kuro bi
ṣiri itú ọkabàba.
25 Njẹ, bi kò ba ri bẹ̃ nisisiyi, tani yio
mi li eké, ti yio si fi ọ̀rọ mi ṣe
inidi?

## ORI 25.

NIGBANA ni Bildadi, ara Ṣua, dahùn
wipe,
2 Ijọba ati ẹ̀ru mbẹ lọdọ rẹ̀, on ni iṣe
ilaja ni ibi gigagiga rẹ̀.
3 Awọn ọmọ-ogun rẹ̀ ha ni iye bi, tabi
ara tani imọlẹ rẹ̀ kò mọ́ si?
4 Eha ti ṣe ti a o fi da enia lare lọdọ
Ọlọrun, tabi ẹniti a bi lati inu obirin wá
yio ha ṣe mọ́?
5 Kiyesi i, òṣupa kò si le itan imọlẹ, ani
awọn ìrawọ kò mọlẹ li oju rẹ̀.
6 Ambọtori enia ti iṣe idin, ati ọmọ enia,
ti iṣe kòkoro!

## ORI 26.

SUGBỌN Jobu si dahùn wipe,
2 Bawo ni iwọ nṣe iranlọwọ ẹniti kò
ni ipá, bawo ni iwọ nṣe gbà apa ẹniti kò li
agbara?
3 Bawo ni iwọ nṣe ìgbimọ ẹniti kò li
ọgbọ́n, tabi bawo ni iwọ nsọdi ọ̀ran li ọ̀pọ-
lọpọ bi o ti ri?
4 Tani iwọ mbà sọ̀rọ, ati ẹmi tani o ti
ọdọ rẹ wá?
5 Awọn alailagbara ti isa-okú wáriri;
labẹ omi pẹlu awọn ti ngbe inu rẹ̀.
6 Ihoho ni ipo-okú niwaju rẹ̀, ibi iparun
kò si ni iboju.
7 On ni o nà ìha ariwa ọrun ni ibi ofu-
rufu, o si fi aiye rọ̀ li oju ofo.
8 O di omiyomi pọ̀ ninu awọsanma rẹ̀
ti o nipọn; awọsanma kò si ya nisalẹ
wọn.
9 O si fa oju itẹ rẹ̀ sẹhin, o si tẹ awọ-
sanma rẹ̀ si i lori.
10 O fi ìde yi omi-okun ka, titi de ala
imọlẹ ati òkunkun.
11 Ọwọn òpó ọrun wáriri, ẹnu si yà wọn
si ibawi rẹ̀.
12 O fi ipa rẹ̀ damu omi-okun, nipa oye
rẹ̀ o lu agberaga jalẹjalẹ.
13 Nipa ẹmi rẹ̀ li o ti ṣe ọrun li ọ̀ṣọ,
ọwọ rẹ̀ li o ti da Ejo-wiwọ nì.
14 Kiyesi i, eyi ni opin ọ̀na rẹ̀, ohùn
eyiti a gbọ́ ti kere tó; ṣugbọn ãra ipá rẹ̀
tali oye rẹ̀ le iye?

## ORI 27.

PẸLUPẸLU Jobu si tun sọ kún ọ̀rọ owe
rẹ̀ o si wipe,
2 Bi Ọlọrun ti mbẹ ẹniti o gba idajọ
mi lọ, ati Olodumare ti o bà mi li ọkàn
jẹ.

Digitized by Google

3 Niwọn igba ti ẹmi mi mbẹ ninu mi,
ati ti ẹmi Ọlọrun mbẹ ni iho imú mi.
4 Ete mi kì yio sọ̀rọ eké, bẹ̃li ahọn mi
kì yio sọ̀rọ ẹ̀tan.
5 Ki a ma ri pe emi ndá nyin li are, titi
emi o fi kú emi kì yio ṣi ìwa otitọ mi kuro
lọdọ mi.
6 Ododo mi li emi dimú ṣinṣin, emi kì
yio si jọwọ rẹ̀ lọwọ; aiya mi kì yio si gan
ọjọ kan ninu ọjọ aiye mi.
7 Ki ọta mi ki o dàbi enia buburu, ati
ẹniti ndide si mi ki o dàbi ẹni alaiṣododo.
8 Nitoripe kini ireti àgabagebe, nigbati
Ọlọrun ba ke ẹmi rẹ̀ kuro, nigbati o si fà
a jade.
9 Ọlọrun yio ha gbọ́ adura rẹ̀, nigbati
ipọnju ba de si i?
10 On ha le ni inu-didùn si Olodumare,
on ha le ma kepe Ọlọrun nigbagbogbo?
11 Emi o kọ́ nyin li ẹkọ́ niti ọwọ Ọlọrun:
eyi ti mbẹ lọdọ Olodumare li emi kì yio fi
pamọ.
12 Kiyesi i, gbogbo nyin li o ti ri i, nitori
kili ẹnyin ṣe jasi asan pọ̀ bẹ̃?
13 Eyi ni ipín enia buburu lọdọ Ọlọrun,
ati ogún awọn aninilara, ti nwọn o gbà
lọwọ Olodumare.
14 Bi awọn ọmọ rẹ̀ ba di pupọ̀, fun
idà ni, awọn ọmọ-ọmọ rẹ̀ kì yio yo fun
onjẹ.
15 Awọn ti o kù ninu tirẹ̀ li a o sinkú
ninu ajakalẹ̀ àrun: awọn opó rẹ̀ kì yio si
sọkún.
16 Bi o tilẹ kó fàdaka jọ bi erupẹ, ti o
si da aṣọ jọ bi amọ̀.
17 Ki o ma dá a, ṣugbọn awọn olõtọ
ni yio lò o; awọn alaiṣẹ̀ ni yio si pin
fadaka na.
18 On kọ́ ile rẹ̀ bi kòkoro aṣọ, ati bi
agọbukà ti oluṣọ pa.
19 Ọlọrọ̀ yio dubulẹ, ṣugbọn on kì o tún
ṣe bẹ̃ mọ́, o ṣiju rẹ̀, on kò sì si.
20 Ẹ̀ru nla bà a bi omi ṣiṣan, ẹ̀fufu nla
ji i gbe lọ li oru.
21 Ẹfufu ila-õrùn gbe e lọ, on si lọ; ati
bi iji nla o si fà a kuro ni ipo rẹ̀.
22 Nitoripe Olodumare yio kọlù u, kì
o sì dasi; on iba yọ̀ lati sá kuro li ọwọ
rẹ̀.
23 Awọn enia yio si ṣapẹ si i lori, nwọn
o si ṣe ṣiọ si i kuro ni ipò rẹ̀.

## ORI 28.

NITÕTỌ ipa-ilẹ fàdaka mbẹ, ati ibi ti
nwọn a ma idà wura.
2 Ninu ilẹ li a gbe nwà irin, bàba li a si
ndà lati inu okuta wá.
3 Enia li o pari òkunkun, o si ṣe awari
okuta òkunkun ati ti inu ojiji ikú si iha
gbogbo.
4 Nwọn wá iho ilẹ ti o jìn si awọn ti o
ngbe oke, awọn ti ẹsẹ enia gbagbe nwọn
rọ si isalẹ, nwọn rọ si isalẹ jina si awọn
enia.
5 Bi o ṣe ti ilẹ ni, ninu rẹ̀ ni onjẹ ti
ijade wá, ati ohun ti o wà nisalẹ li o yi
soke bi ẹnipe iná.
6 Okuta ibẹ ni ibi okuta Safiri, o si ni
erupẹ wura.
7 Ipa ọ̀na na ni ẹiyẹ kò mọ̀, ati oju gunugun
kò ri i ri.
8 Awọn ọmọ kiniun kò rin ibẹ rí, bẹ̃ni
kiniun ti nké ramuramu kò kọja nibẹ rí.
9 O fi ọwọ rẹ̀ le akọ apata, o yi okenla
po lati idi rẹ̀ wá.
10 O si la ipa-odò ṣiṣàn ninu apata, oju
rẹ̀ si ri ohun iyebiye gbogbo.
11 O si sé iṣàn odò ki o má ṣe kún akunya,
o si mu ohun ti o lumọ hàn jade wá
si imọlẹ.
12 Ṣugbọn nibo li a o gbe wá ọgbọ́n ri,
nibo si ni ibi oye?
13 Enia kò mọ̀ iye rẹ̀, bẹ̃li a kò le iri i
ni ilẹ awọn alãyè.
14 Ọgbun wipe, kò si ninu mi, omi-okun
si wipe, kò si ninu mi.
15 A kò le fi wura rà a, bẹ̃li a kò le ifi
òṣuwọn wọ̀n fadaka ni iye rẹ̀.
16 A kò le fi wura Ofiri diyele e, pẹlu
okuta oniksi iyebiye, ati okuta Safiri.
17 Wura ati okuta kristali kò to ẹgbẹ́
rẹ̀, bẹ̃li a kò le fi ohun-èlo wura ṣe paṣiparọ
rẹ̀.
18 A kò le idarukọ iyun tabi okuta
perli; iye ọgbọ́n si jù okuta rubi lọ.
19 Okuta topasi ti Etiopia kò tó ẹgbẹ́
rẹ̀, bẹ̃li a kò le ifi wura daradara diye
le e.
20 Nibo ha li ọgbọn ti jade wá; tabi
nibo ni ibi oye?
21 A ri pe, o lumọ kuro li oju awọn
alãyè gbogbo, o si fara sin fun ẹiyẹ oju
ọrun.
22 Ibi iparun (Abaddoni) ati ikú wipe,
Awa ti fi etí wa gburo rẹ̀.
23 Ọlọrun li o moye ipa ọ̀na rẹ̀, o si mọ̀
ipo rẹ̀,
24 Nitoripe o woye de opin aiye, o si ri
gbogbo isalẹ ọrun.
25 Lati dà òṣuwọn fun afẹfẹ, o si fi òṣuwọn
wọ̀n omiyomi.

Digitized by Google

26 Nigbati o paṣẹ fun òjo, ti o si la ọ̀na
fun mànamana ãrá:
27 Nigbana li o ri i, o si sọ ọ jade, o
pèse rẹ̀ silẹ, ani o si wadi rẹ̀ ri.
28 Ati fun enia li o wipe, kiyesi i; Ẹru
Oluwa, eyi li ọgbọ́n, ati lati jade kuro ninu
ìwa-buburu eyi li oye!

## ORI 29.

PẸLUPẸLU Jobu si tun gbẹnu le ọ̀rọ rẹ̀
o si wipe,
2 A! ibaṣepe emi wà bi igba oṣu ti o
kọja, bi ọjọ ti Ọlọrun pa mi mọ́!
3 Nigbati fitila rẹ̀ tàn si mi li òri, ati
nipa imọlẹ rẹ̀ emi rìn ninu òkunkun ja.
4 Bi mo ti ri nigba ọ̀dọ́ mi, nigbati aṣiri
Ọlọrun wà ninu agọ mi.
5 Nigbati Olodumare wà sibẹ pẹlu mi,
nigbati awọn ọmọ mi wà yi mi ka.
6 Nigbati emi nfi ori-amọ wẹ̀ iṣisẹ mi,
ati ti apata ntú iṣàn ororo jade fun mi wá.
7 Nigbati mo jade là arin ilu lọ si ẹnu
ibode, nigbati mo tẹ ìtẹ mi ni igboro.
8 Nigbana ni awọn ọdọmọkọnrin ri mi,
nwọn si sapamọ́, awọn àgba dide duro.
9 Awọn ọmọ-alade dakẹ ọ̀rọ sisọ, nwọn
a si fi ọwọ wọn le ẹnu.
10 Awọn ọlọla dakẹ, ahọn wọn si lẹmọ
èrigi ẹnu wọn.
11 Nitoripe eti gbọ́ ti emi, a si sure fun
mi, oju si ri mi, on a jẹri mi.
12 Nitoriti mo gba talaka ti nsọkun, ati
alainibaba, ati alaini oluranlọwọ.
13 Isure ẹniti o fẹrẹ iṣegbe wa si ori mi,
emi si mu aiya opo kọrin fun ayọ̀.
14 Emi si mu ododo wọ̀, o si bò mi
lara; idajọ mi dabi aṣọ igunwa ati ade
ọba.
15 Mo ṣe oju fun afọju, ati ẹsẹ̀ fun
amọkún.
16 Mo ṣe baba fun talaka, ati ọ̀ran ti
emi kò mọ̀, mo wadi rẹ̀ ri.
17 Mo si ká ehin ẹrẹkẹ enia buburu, mo
si ja ohun ọdẹ na kuro li ehin rẹ̀.
18 Nigbana ni mo wipe, emi o kú ninu
itẹ mi, emi o si mu ọjọ mi pọ̀ si i bi iyan-
rin. (bi ọjọ ti ẹiyẹ Feniksi.)
19 Gbongbo mi ta lọ si ibi omi, ìri si sẹ̀
si ara ẹká mi titi li oru.
20 Ogo mi gberu lọdọ mi, ọrun mi si
pada di titun li ọwọ mi.
21 Emi li enia ndẹti silẹ si, nwọn a si
duro, nwọn a si dakẹ ninu ìgbimọ mi.
22 Lẹhin ọ̀rọ mi nwọn kò si tun sọ mọ́,
ọ̀rọ mi bọ́ si wọn li eti.
23 Nwọn a si duro dè mi bi ẹnipe fun
ojo; nwọn si yanu wọn gboro bi ẹnipe fun
ojo àrọ-kuro.
24 Emi si rẹrin si wọn nigbati nwọn kò
ba gba a gbọ́; imọlẹ ọju mi ni nwọn kò le
imu rẹ̀wẹsi.
25 Mo la ọ̀na silẹ fun wọn, mo si joko
bi Olu, mo si joko bi ọba ninu ogun, bi
ẹniti ntù aṣọ̀fọ̀ ninu.

## ORI 30.

SUGBỌN nisisiyi awọn ti mo gbà li aburo
nfi mi ṣẹ̀sin, baba ẹniti emi kẹgàn lati
tò pẹlu awọn ajá agbo-ẹran mi.
2 Pẹlupẹlu agbara ọwọ wọn kini o le
igbè fun mi, awọn ẹniti kikún ọjọ wọn kò
si.
3 Nitori aini ati ìyan nwọn di ẹni itake-
te, nwọn si girijẹ ohun jijẹ iju, ti o wà ni
jũjũ ati ẽtu lati lailai.
4 Awọn ẹniti njá ewe-iyọ li ẹ̀ba igbẹ,
gbongbo igikigi li ohun jijẹ wọn.
5 A le wọn jade kuro lãrin enia, nwọn si
ho le wọn bi ẹnipe si olè.
6 Lati gbé inu pàlapala okuta afoni-
foji, ninu iho ilẹ ati ti okuta.
7 Ninu igbẹ ni nwọn ndún, nwọn ko ara
wọn jọ pọ̀ labẹ ẹgun neteli.
8 Awọn ọmọ ẹniti oye kò ye, ani ọmọ
awọn enia lasan, a si le wọn kuro ninu ilẹ.
9 Njẹ nisisiyi emi di ẹni-orin fun wọn,
ani emi di ẹni-asọrọsi fun wọn.
10 Nwọn korira mi, nwọn sa kuro jina
si mi, nwọn kò si dá si lati tutọ́ si mi loju.
11 Nitoriti Ọlọrun ti tu okun-ìye mi, o
si pọn mi loju; awọn pẹlu si dẹ̀ ijanu ni-
waju mi.
12 Awọn enia lasan dide li apa ọ̀tun mi,
nwọn tì mi li ẹsẹ kuro, nwọn si là ipa-ọ̀na
iparun silẹ dè mi.
13 Nwọn dà ipa-ọ̀na mi rú, nwọn ran
jàmba mi lọwọ, awọn ti kò li oluranlọwọ;
14 Nwọn de si mi bi yiya omi gburu, ni
ariwo nla ni nwọn ko ara wọn kátì si mi.
15 Ẹru nla yipada bà mi, nwọn lepa
ọkàn mi bi ẹfũfù, alafia mi si kọja lọ bi
awọsanma.
16 Ati nisisiyi ọkàn mi si dà jade si mi,
ọjọ ipọnju dì mi mu.
17 Oru gùn mi ninu egungun mi, eyiti
o bù mi jẹ kò si simi.
18 Nipa agbara nla aṣọ mi di pipada, o
si lẹmọ́ mi li ara yika bi ọrùn aṣọ ileke mi.
19 O ti mu mi lọ sinu ẹrẹ̀, emi si dabi
ekuru ati ẽru,
20 Emi kepè ọ, iwọ kò si gbọ́ ti emi, emi
dide duro, iwọ si fi oju lile wò mi.

Digitized by Google

21 Iwọ pada di ẹni-ìka si mi, ọwọ agba-
ra rẹ ni iwọ fi de ara rẹ li ọ̀na si mi.
22 Iwọ gbe mi soke si ẹ̀fufu, iwọ mu mi
fò lọ, bẽni iwọ si sọ mi di asan patapata.
23 Emi sa mọ̀ pe iwọ o mu mi lọ sinu
ikú, ati si ile-apejọ fun gbogbo alãye.
24 Bi o ti wu ki o ṣe, ẹnikan kì yio ha
nawọ rẹ̀ ni igba iṣubu rẹ̀, tabi kì yio ké
ninu iparun rẹ̀.
25 Emi kò ha sọkun bi fun ẹniti o wà
ninu iṣẹ, ọkàn mi kò ha bajẹ fun talaka
bi?
26 Nigbati mo fojusọna fun alafia, ibi si
de, nigbati emi duro de imọlẹ, òkunkun si
de.
27 Ikún mi nru, kò si simi, ọjọ ipọnju
ti bá mi.
28 Emi nṣọ̀fọ lọ rinkiri laisi õrùn, emi
dide duro ni awujọ, mo si kigbe.
29 Emi jasi arakọnrin ajáko, emi di ẹgbẹ́
awọn abo-ogongo.
30 Awọ mi di dudu li ara mi, egungun
mi si jórun fun õru.
31 Dùru mi pẹlu si di ti ọ̀fọ, ati ohun-
ọnà orin mi si di ohùn awọn ti nsọkún.

## ORI 31.

EMI ti bá oju mi da majẹmu, njẹ emi o
ha ṣe tẹjumọ wundia?
2 Nitoripe kini ipin Ọlọrun lati ọrun
wá, tabi kini ogún Olodumare lati oke
ọrun wá?
3 Kò ṣepe awọn enia buburu ni iparun
wà fun, ati ìṣẹniṣẹ fun awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ?
4 On kò ha ri ipa-ọ̀na mi, on kò ha si ka
gbogbo iṣiṣe mi?
5 Bi o ba ṣepe emi ba fi aiṣotitọ rìn, tabi
ti ẹsẹ mi si yara si ẹ̀tan.
6 Ki a diwọn mi ninu iwọ̀n ododo, ki
Ọlọrun le imọ̀ iduroṣinṣin mi.
7 Bi ẹsẹ mi ba yà kuro loju ọ̀na, ti aiya
mi si tẹ̀le ipa oju mi, bi àbawọn kan ba si
lẹmọ́ mi li ọwọ.
8 Njẹ ki emi ki o gbìn ki ẹlomiran ki o
si mu u jẹ, ani ki a fà iru-ọmọ mi tu.
9 Bi aiya mi ba di fifa sipasẹ obirin kan,
tabi bi mo ba lọ ibadeni li ẹnu-ọ̀na ile ala-
dugbo mi,
10 Njẹ ki aya mi ki o lọ ọlọ fun ẹlomi-
ran, ki awọn ẹlomiran ki o tẹ́ ara wọn li
ara rẹ̀.
11 Nitoripe ẹ̀ṣẹ buburu li eyi; ani ẹ̀ṣẹ
ìṣẹniṣẹ ni lọdọ awọn onidajọ.
12 Nitoripe iná ni eyi ti o jo de iparun,
ti iba si fà gbongbo ohun ibisi mi gbogbo tu.
13 Bi mo ba si ṣe aikà ọ̀ran iranṣẹ-kọnrin
mi tabi iranṣẹbirin mi si, nigbati nwọn ba
mba mi jà;
14 Kili emi o ha ṣe nigbati Ọlọrun ba
dide; nigbati o ba si ṣe ibẹwo, ohùn kili
emi o dá?
15 Ẹniti o dá mi ni inu kọ li o da a?
ẹnikanna ki o mọ wa ni inu?
16 Bi mo ba fà ọwọ sẹhin fun ifẹ-inu
talaka, tabi bi mo ba si mu oju opó mofo?
17 Tabi ti mo ba nikan bu òkele mi jẹ,
ti alainibaba kò jẹ ninu rẹ̀;
18 Nitoripe lati igba ewe mi wá li a ti
tọ́ ọ dàgba pẹlu mi bi ẹnipe baba, emi si
nṣe itọju rẹ̀ (opó) lati inu iya mi wá.
19 Bi emi ba ri olupọnju laini aṣọ, tabi
talaka kan laini ibora;
20 Bi ẹgbẹ rẹ̀ kò ba sure fun mi, tabi bi
ara rẹ̀ kò si gbona nipaṣe irun agutan mi.
21 Bi mo ba si gbe ọwọ mi soke si alai-
nibaba, nitoripe mo ri iranlọwọ mi li ẹnu-
bode,
22 Njẹ ki apá mi ki o wọ́n kuro li ọkọ́
ejika rẹ̀, ki apá mi ki o si ṣẹ́ lati egungun
rẹ̀ wá.
23 Nitoripe iparun lati ọdọ Ọlọrun wá
ni ẹ̀ru-nla fun mi, ati nitori Ọlanla rẹ̀ emi
kò le iduro.
24 Bi o ba ṣepe mo fi wura ṣe igbẹkẹle
mi, tabi bi mo ba wi fun wura didara pe,
iwọ ni igbẹkẹlẹ mi;
25 Bi mo ba yọ̀ nitori ọrọ̀ mi pọ̀, ati
nitori ọwọ mi dẹ̀ lọpọlọpọ;
26 Bi mo ba bojuwo õrùn nigbati nràn,
tabi òṣupa ti nrin ninu itan-imọlẹ,
27 Ti aiya mi si di titan, lati fi ẹnu mi
kò ọwọ mi:
28 Eyi pẹlu li ẹ̀ṣẹ ìṣẹniṣẹ lọdọ awọn oni-
dajọ, nitoripe emi iba sẹ́ Ọlọrun ti o wà
loke.
29 Bi o ba ṣepe mo yọ̀ si iparun ẹniti o
korira mi, tabi bi mo ba si gbera soke,
nigbati ibi bá a.
30 Bẹ̃li emi kò si jẹ ki ẹnu mi ki o ṣẹ̀
nipa fifẹ egún si ọkàn rẹ̀.
31 Bi awọn enia inu agọ mi kò ba le
wipe, Tali o le ri ẹniti agbo-ẹran rẹ̀ kò
tẹlọrùn?
32 Alejo kò wọ̀ ni igboro ri, emi ṣi ilẹ̀-
kun mi silẹ fun èro.
33 Bi mo ba bò irekọja mi mọlẹ bi
Adamu, ni pipa ẹbi mi mọ́ li aiya mi:
34 Ọ̀pọlọpọ enia ni mo ha bẹ̀ru bi, tabi
ẹ̀gan awọn idile ni mba mi li ẹ̀ru? ti mo fi
pa ẹnu mọ́, ti emi kò si fi jade sode?
35 Ibaṣepe ẹnikan le gbọ́ ti emi! kiyesi

Digitized by Google

i, àmi mi! ki Olodumare ki o da mi lohùn!
ki emi ki o si ri iwe na ti ọta mi ti kọ!
36 Nitõtọ emi iba gbe e le ejika mi, emi
iba si dì i bi ade mọ́ ori mi.
37 Emi iba si sọ iye ìṣisẹ mi fun u, bi
ọmọ-alade li emi iba sunmọ ọdọ rẹ̀.
38 Bi ilẹ mi ba si ke fi mi sùn, tabi ti
aporo rẹ̀ pẹlu si sọkun,
39 Bi mo ba jẹ eso oko mi lainawo si i,
tabi ti mo si mu ọkàn oluwa rẹ̀ fò lọ,
40 Ki ẹgun òṣuṣu ki o hù nipo alikama,
ati wèpe nipo ọka-bàba. (Ọ̀rọ Jobu pari.)

## ORI 32.

BẸ̃NI awọn ọkọnrin mẹtẹta wọnyi dakẹ
lati da Jobu lohùn, nitori o ṣe olododo
loju ara rẹ̀.
2 Nigbana ni inu bi Elihu, ọmọ Bara-
keli, ara Busi, lati ibatan idile Ramu; o
binu si Jobu, nitoriti o da ara rẹ̀ lare kàka
ki o da Ọlọrun lare.
3 Inu rẹ̀ si bi si awọn ọ̀rẹ rẹ̀ mẹtẹta,
nitoriti nwọn kò ni idahùn, bẹ̃ni nwọn dá
Jobu lẹbi.
4 Njẹ Elihu ti duro titi Jobu fi sọ̀rọ tan,
nitoriti awọn wọnyi dàgba jù on lọ ni iye
ọjọ.
5 Nigbati Elihu ri pe idahùn ọ̀rọ kò si
li ẹnu awọn ọkọnrin mẹtẹta wọnyi, nigbana
ni o binu.
6 Elihu, ọmọ Barakeli, ara Busi, dahùn
o si wipe, Ọmọde li emi, àgba si li ẹnyin;
njẹ nitorina ni mo duro, mo si mbẹ̀ru lati
fi ìmọ mi hàn nyin.
7 Emi wipe, ọjọ-jọjọ ni iba sọ̀rọ, ati ọ̀pọ-
lọpọ ọdun ni iba ma kọ́ni li ọgbọ́n.
8 Ṣugbọn ẹmi kan ni o wà ninu enia, ati
imisi Olodumare ni isi ma fun wọn li oye.
9 Enia nlanla kì iṣe ọlọgbọ́n, bẹ̃ni awọn
àgba li oye idajọ kò ye.
10 Nitorina li emi ṣe wipe, ẹ dẹtisilẹ si
mi, emi pẹlu yio fi ìmọ mi hàn.
11 Kiyesi i, emi ti duro de ọ̀rọ nyin, emi
fetisi aroye nyin, nigbati ẹnyin nwá ọ̀rọ ti
ẹnyin o sọ.
12 Ani mo fiyesi nyin tinutinu, si kiyesi
i, kò si ẹnikan ninu nyin ti o le iṣi Jobu
li aje, tabi ti o lè ida a lohùn ọ̀rọ rẹ̀!
13 Ki ẹnyin ki o má ba wipe, awa wá
ọgbọ́n li awari: Ọlọrun li o lè bi i ṣubu, kì
iṣe enia.
14 Bi on kò ti sọ̀rọ si mi, bẹ̃li emi kì yio
fi ọ̀rọ nyin da a lohùn.
15 Ẹnu si yà wọn, nwọn kò si dahùn
mọ, nwọn ṣiwọ ọ̀rọ isọ.
16 Mo si reti, nitoriti nwọn kò si fọhùn,
nwọn dakẹ jẹ, nwọn kò si dahùn mọ́.
17 Bẹ̃li emi o si dahùn nipa ti emi, emi
pẹlu yio si fi ìmọ mi hàn.
18 Nitoripe emi kún fun ọ̀rọ sisọ, ẹmi
nrọ̀ mi ni inú mi.
19 Kiyesi i, ikùn mi dabi ọti-waini, ti
kò ni oju-iho; o mura tan lati bẹ́ bi igo-
awọ titun.
20 Emi o sọ, ki ara ki o le rọ̀ mi, emi o
ṣi ète mi, emi o si dahùn.
21 Lotitọ emi kì yio ṣe ojusaju enia,
bẹ̃li emi kì yio si ṣe ipọnni fun ẹnikan.
22 Nitoripe emi kò mọ̀ ọ̀rọ ipọnni sọ, ni
ṣiṣe bẹ̃ Ẹlẹda mi yio mu mi kuro lọgan.

## ORI 33.

NJẸ nitorina, Jobu, emi bẹ̀ ọ, gbọ́ ọ̀rọ
mi, ki o si fetisi ọ̀rọ mi!
2 Kiyesi i nisisiyi, emi ya ẹnu mi, ahọn
mi si sọ̀rọ li ẹnu mi.
3 Ọ̀rọ mi yio si jasi iduroṣinṣin ọkàn mi,
ète mi yio si sọ ìmọ mi jade dajudaju.
4 Ẹmi Ọlọrun li o ti da mi, ati imisi
Olodumare li o ti fun mi ni ìye.
5 Bi iwọ ba le da mi lohùn, tò ọ̀rọ rẹ
lẹsẹsẹ niwaju mi, dide duro!
6 Kiyesi i, bi iwọ jẹ ti Ọlọrun, bẹ̃li emi
na; lati erupẹ wá ni a si ti dá mi pẹlu.
7 Kiyesi i, ẹ̀ru nla mi kì yio bà ọ, bẹ̃li
ọwọ mi kì yio wuwo si ọ lara.
8 Nitõtọ iwọ sọ li eti mi, emi si gbọ́ ọ̀rọ
rẹ wipe,
9 Emi mọ́, laini irekọja, alaiṣẹ li emi,
bẹ̃li aiṣedede kò si li ọwọ mi.
10 Kiyesi i, ẹ̀fẹ li o fẹ si mi, o kà mi si
ọ̀ta rẹ̀.
11 O kàn ẹsẹ mi sinu àba, o kiyesi ipa-
irin mi gbogbo.
12 Kiyesi i, ninu eyi iwọ ṣina! emi o da
ọ lohùn pe: Ọlọrun tobi jù enia lọ!
13 Nitori kini iwọ ṣe mba a jà pe: on
kì iṣirokiro kan nitori iṣẹ rẹ̀?
14 Nitoripe Ọlọrun sọ̀rọ lẹkan, ani lẹke-
ji ṣugbọn enia kò roye rẹ̀.
15 Ninu àla, li ojuran oru, nigbati orun
ìjika ba kùn enia lọ, ni isunyẹ lori bùsun.
16 Nigbana ni iṣi eti enia, a si fi èdidi di
ẹkọ wọn.
17 Ki o lè ifa enia sẹhin kuro ninu ete
rẹ̀, ki o si pa igberaga mọ́ kuro lọdọ enia.
18 O si fa ọkàn rẹ̀ pada kuro ninu iho,
ati ẹmi rẹ̀ lati ṣègbe lọwọ idà.
19 A si fi irora nà a lori ibùsun rẹ̀, pẹlu-
pẹlu a fi ijà egungun rẹ̀ ti o duro pé, nà a.

Digitized by Google

20 Bẹ̃li ẹmi rẹ̀ kọ̀ onjẹ, ati ọkàn rẹ̀ kọ̀
onjẹ didùn.
21 Ẹran ara rẹ̀ rùn, titi a kò si fi lè ri i
mọ́; egungun rẹ̀ ti a kò ri, si ta jade.
22 Ani ọkàn rẹ̀ sunmọ isa-okú, ati ẹmi
rẹ̀ sunmọ ọdọ awọn iranṣẹ iku.
23 Bi onṣẹ kan ba wà lọdọ rẹ̀, ẹniti nṣe
alagbawi, ọkan ninu ẹgbẹrun lati fi ọ̀na
pipé han ni:
24 Nigbana ni o ṣore-ọfẹ fun u, o si wipe,
Gbà a kuro ninu ilọ sinu ihò, emi ti ri ira-
pada!
25 Ara rẹ̀ yio si já yọ̀yọ̀ jù ti ọmọ keke-
re, yio si tún pada si ọjọ igba ewe rẹ̀.
26 O gbadura sọdọ Ọlọrun, on o si ṣe oju
rere si i, o si mu enia ri oju rẹ̀ pẹlu ayọ̀,
on o san ododo rẹ̀ pada fun enia.
27 O bojuwo enia, bi ẹnikan ba si wipe,
Emi ṣẹ̀, mo si ti yi eyi ti o tọ́ po, a kò si
sẹsan rẹ̀ fun mi;
28 O ti gba ọkàn mi kuro ninu ilọ sinu
ihò, ẹmi mi yio si ri imọlẹ!
29 Wò o! nkan wọnyi li Ọlọrun imaṣe
fun enia nigba meji, ati nigba mẹta,
30 Lati mu ọkàn rẹ̀ pada kuro ninu ihò,
lati fi imọlẹ alãyè mọ́ si i.
31 Jobu! kiyesi i gidigidi, ki o si feti-
silẹ si mi; pa ẹnu rẹ mọ́, emi o si ma sọ!
32 Bi iwọ ba si ni ohun iwi, da mi
lohùn, mã sọ, nitoripe emi nfẹ da ọ lare.
33 Bi bẹ̃ kọ̀, gbọ temi, pa ẹnu rẹ mọ́;
emi o si kọ́ ọ li ọgbọ́n.

## ORI 34.

PẸLUPẸLU Elihu dahùn o si wipe,
2 Ẹnyin ọlọgbọ́n, ẹ gbọ́ ọ̀rọ mi, ki ẹ
si dẹtisilẹ si mi, ẹnyin ti ẹ ni ìmoye.
3 Nitoripe eti a ma dán ọ̀rọ wò, bi adùn
ẹnu ti itọ onjẹ wò.
4 Ẹ jẹ ki a ṣà idajọ yàn fun ara wa; ẹ
jẹ ki a mọ̀ ohun ti o dara larin wa.
5 Nitoripe Jobu wipe, Olododo li emi;
Ọlọrun si ti gbà idajọ mi lọ.
6 Emi ha lè ipurọ si itọsí mi bi, ọfa mi
kò ni awọtan, laiṣẹ ni.
7 Ọkọnrin wo li o dabi Jobu, ti nmu
ẹ̀gan bi ẹni mu omi.
8 Ti mba awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ kẹgbẹ, ti o si
mba awọn enia buburu rin.
9 Nitori o sa ti wipe, Ere kan kò si fun
enia, ti yio fi ma ṣe inu didun si Ọlọrun,
10 Njẹ nitorina, ẹ fetisilẹ si mi, ẹnyin
enia amoye: odõdi fun Ọlọrun ti iba fi
huwa buburu, ati fun Olodumare, ti yio fi
ṣe aiṣedede!
11 Nitoripe ẹsan iṣẹ enia ni yio san fun
u, yio si mu olukuluku ki o ri gẹgẹ bi ipa-
ọ̀na rẹ̀.
12 Nitõtọ Ọlọrun kì yio hùwakiwa, bẹ̃ni
Olodumare kì yio yi idajọ po.
13 Tani o fi itọju aiye lé e lọwọ, tabi
tali o to gbogbo aiye lẹsẹlẹsẹ?
14 Bi o ba gbe aiya rẹ̀ le kiki ara rẹ̀, ti
o si gba ọkàn rẹ̀ ati ẹmi rẹ̀ sọdọ ara rẹ̀,
15 Gbogbo enia ni yio parun pọ̀, enia a
si tun pada di erupẹ.
16 Njẹ nisisiyi, bi iwọ ba ni oye, gbọ́
eyi, fetisi ohùn ẹnu mi.
17 Ẹniti o korira otitọ le iṣe olori bi?
iwọ o ha si da olõtọ-ntọ̀ lẹbi?
18 O ha tọ́ lati wi fun ọba pe, Enia bu-
buru ni iwọ, tabi fun awọn ọmọ-alade, pe,
Alaimọ-lọrun li ẹnyin?
19 Ambọtori fun ẹniti kì iṣojusaju awọn
ọmọ-alade, tabi ti kò kà ọlọrọ̀ si jù talaka
lọ, nitoripe iṣẹ ọwọ rẹ̀ ni gbogbo wọn iṣe.
20 Ni iṣẹju kan ni nwọn o kú, awọn
enia a si di yiyọ lẹnu larin ọganjọ, nwọn a
si kọja lọ; a si mu awọn alagbara kuro
laifiọwọ ṣe.
21 Nitoripe oju rẹ̀ mbẹ ni ipa-ọ̀na enia,
on si ri irin rẹ̀ gbogbo.
22 Kò si òkunkun, tabi ojiji ikú, nibiti
awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ yio gbe sapamọ si.
23 Nitoripe on kò pẹ ati kiyesi ẹnikan,
ki on ki o si mu u lọ sinu idajọ niwaju
Ọlọrun.
24 On o fọ awọn alagbara tútu laini-
iwadi, a si fi ẹlomiran dipo wọn,
25 Nitoripe o mọ̀ iṣẹ wọn, o si yi wọn
po di oru, bẹ̃ni nwọn di itẹ̀rẹ́ pọ̀.
26 O kọlu wọn bi enia buburu, nibiti
awọn ẹlomiran ri i.
27 Nitorina ni nwọn pada kẹhinda si i,
nwọn kò si ti fiyesi ipa-ọ̀na rẹ̀ gbogbo.
28 Ki nwọn ki o si mu igbe ẹkún awọn
talaka lọ de ọdọ rẹ̀, on si gbọ́ igbe ẹkún
olupọnju.
29 Nigbati o ba fun ni ni irọra, tani yio
da a lẹbi, nigbati o ba pa oju rẹ̀ mọ, tani
yio le iri i? bẹ̃ni o ṣe e si orilẹ-ède tabi si
enia kanṣoṣo.
30 Ki agabagebe ki o má ba jọba, ki
nwọn ki o má di idẹwo fun enia.
31 Nitoripe ẹnikan ha le wi fun Ọlọrun
pe, emi jiya laiṣẹ̀?
32 Eyi ti emi kò ri, iwọ fi kọ́ mi, bi mo
ba si dẹṣẹ, emi kì yio ṣe bẹ̃ mọ́.
33 Iṣe bi ti inu rẹ pe, on o san ẹ̀ṣẹ pada!
njẹ on yio san a pada, iwọ iba kọ̀ ọ tabi
iwọ iba fẹ ẹ, kì iṣe emi, pẹlupẹlu kili iwọ
mọ̀, sọ ọ!

Digitized by Google

34 Awọn enia amoye yio wi fun mi, ati
pẹlupẹlu ẹnikẹni ti nṣe ọlọgbọ́n, ti o si gbọ́
mi.
35 Jobu ti fi aimọ̀ sọ̀rọ, ọ̀rọ rẹ̀ si ṣe
alaigbọ́n.
36 Ifẹ mi ni ki a dán Jobu wò de opin,
nitori idahùn rẹ̀ nipa ọ̀na enia buburu;
37 Nitoripe o fi iṣọtẹ kún ẹ̀ṣẹ rẹ̀, o papẹ́
li awujọ wa, o si sọ ọ̀rọ di pupọ si Ọlọrun.

## ORI 35.

ELIHU sọ pẹlu o si wipe,
2 Iwọ rò pe eyi ha tọ́, ti iwọ wipe,
ododo mi ni eyi niwaju Ọlọrun pe,
3 Nitoriti iwọ wipe, Ère kini yio jasi
fun ọ, tabi ère kili emi o fi jẹ jù ère ẹ̀ṣẹ
mi lọ?
4 Emi o da ọ lohùn ati awọn ẹgbẹ rẹ
pẹlu rẹ.
5 Ṣiju wò ọrun, ki o ri i, ki o si bojuwo
awọsanma ti o ga jù ọ lọ.
6 Bi iwọ ba ṣẹ̀ kini iwọ fi ṣe si i? tabi
bi irẹkoja rẹ di pupọ, kini iwọ fi eyini ṣe
si i?
7 Bi iwọ ba si ṣe olododo, kini iwọ fi
bùn u, tabi kili on ri gbà lati ọwọ rẹ wá?
8 Ìwa buburu rẹ ni fun enia bi iwọ;
ododo rẹ si ni fun ọmọ enia.
9 Nipa ọ̀pọlọpọ ininilara nwọn mu ni
kigbe, nwọn kigbe nitori apá awọn ala-
gbara.
10 Ṣugbọn kò si ẹniti o wipe, Nibo ni
Ọlọrun Ẹlẹda mi wà, ti o fi orin fun mi li
oru?
11 Ti on kọ́ wa li ẹkọ́ jù awọn ẹranko
aiye lọ, ti o si mu wa gbọ́n jù awọn ẹiyẹ
oju ọrun lọ.
12 Nigbana ni nwọn ke, ṣugbọn Ọlọrun
kò dahùn nitori igberaga awọn enia bu-
buru.
13 Nitõtọ Ọlọrun kì yio gbọ́ asan, bẽni
Olodumare kì yio kà a si.
14 Bi o tilẹ ṣepe iwọ wipe, iwọ kì iri i,
ọran idajọ mbẹ niwaju rẹ̀, ẹniti iwọ si
gbẹkẹle.
15 Ṣugbọn nisisiyi nitoriti ibinu rẹ̀ kò ti
ṣẹ́ ọ niṣẹ, on kò ha le imọ̀ ọ̀pọlọpọ ẹ̀ṣẹ bi?
16 Nitorina ni Jobu ṣe ya ẹnu rẹ̀ lasan,
o sọ ọ̀rọ di pupọ laisi ìmọ.

## ORI 36.

ELIHU si sọ si i lọ wipe,
2 Bùn mi laye diẹ, emi o si fi hàn ọ,
nitori ọ̀rọ sisọ ni o kù fun Ọlọrun.
3 Emi o mu ìmọ mi ti ọ̀na jijin wá, emi
o si fi ododo fun Ẹlẹda mi.
4 Nitoripe ọ̀rọ mi kì yio ṣeke nitõtọ,
ẹniti o pé ni ìmọ wà pẹlu rẹ.
5 Kiyesi i, Ọlọrun li agbara, kò si gàn
ẹnikẹni, o li agbara ni ipá ati oye.
6 On kì ida ẹmi enia buburu sí, ṣugbọn
o fi otitọ fun awọn talaka.
7 On kì imu oju rẹ̀ kuro lara olododo,
ṣugbọn pẹlu awọn ọba ni nwọn wà lori
itẹ; ani o fi idi wọn mulẹ lailai, a si gbe
wọn lekè.
8 Bi a ba si dè wọn ninu àba, ti a si fi
okun ipọnju dè wọn.
9 Nigbana ni ifi iṣẹ wọn hàn fun wọn,
ati irekọja wọn ti nwọn fi gbé ara wọn
ga.
10 O ṣi wọn leti pẹlu si ọ̀na ẹkọ́, o si
paṣẹ ki nwọn ki o pada kuro ninu aiṣedede.
11 Bi nwọn ba gbagbọ, ti nwọn si sin
i, nwọn o lò ọjọ wọn ninu ègbè, ati ọdun
wọn ninu afẹ́.
12 Ṣugbọn bi nwọn kò ba gbagbọ, nwọn
o ti ọwọ idà ṣègbe, nwọn a si kú laini oye.
13 Ṣugbọn awọn àgabagebe li aiya kó
ibinu jọ; nwọn kò kigbe nigbati o ba dè
wọn.
14 Nigbana ni ọkàn wọn yio kú li ewe,
ẹmi wọn a si wà ninu awọn oniwa Sodomu.
15 On gba otoṣi ninu ipọnju rẹ̀, a si ṣi
wọn li eti ninu inilara.
16 Bẽni pẹlupẹlu o si dẹ̀ ọ lọ lati inu
ihagaga si ibi gbòro, ti kò ni wahala ninu
rẹ̀; ati ohun ti a si gbe kalẹ ni tabili rẹ,
a jẹ kiki ọ̀ra.
17 Ṣugbọn iwọ kún fun idajọ awọn enia
buburu; idajọ ati otitọ di ọ mu.
18 Nitori ibinu mbẹ, ṣọra ki titó rẹ ma
bà tàn ọ lọ; má si ṣe jẹ ki titobi irapada
mu ọ ṣina.
19 Ọrọ̀ rẹ pọ̀ to, ti wahala kì yio fi de
ba ọ bi? tabi ipá agbara rẹ?
20 Máṣe fẹ oru, nigbati a nke awọn
orilẹ-ède kuro ni ipo wọn.
21 Ma ṣọra ki iwọ ki o má yi ara rẹ pada
si aṣan, nitori eyi ni iwọ ti ṣàyan jù sũru
lọ.
22 Kiyesi i, Ọlọrun a gbeni ga nipa
agbara rẹ̀, tani jẹ olukọni bi on?
23 Tali o là ọ̀na-iṣẹ rẹ̀ silẹ fun u, tabi
tali o lè wipe, Iwọ ti nṣe aiṣedede?
24 Ranti ki iwọ ki o gbe iṣẹ́ rẹ̀ ga, ti
enia ima kọrin si.
25 Olukuluku enia a ma ri i, ẹni-ikú a
ma wò o li okere.
26 Kiyesi i, Ọlọrun tobi, awa kò si mọ̀
bi o ti tobi to! bẽni a kò le wadi iye ọdun
rẹ̀ ri.

Digitized by Google

27 Nitoripe on li o fa ikán omi ojo silẹ,
ki nwọn ki o kán bi ojo ni ikuku rẹ̀.
28 Ti awọsanma nrọ̀, ti o si nfi sẹ̀ lọpọ-
lọpọ lori enia.
29 Pẹlupẹlu ẹnikẹni le imọ̀ itanká awọ-
sanma, tabi ariwo agọ rẹ̀?
30 Kiyesi i, o tàn imọlẹ yi ara rẹ̀ ka, o
si fi isalẹ omi okun bò ara rẹ̀ mọlẹ.
31 Nitoripe nipa wọn ni nṣe idajọ enia,
o fun ni li onjẹ li ọ̀pọlọpọ.
32 O fi imolẹ bò ọwọ rẹ̀ mejeji, o si ran
a si ẹni olodi.
33 Ariwo ãrá rẹ̀ fi i han ni, ọ̀wọ-ẹran
pẹlu wipe, O sunmọ etile!

## ORI 37.

AIYA si fò mi si eyi pẹlu, o si ṣi kuro ni
ipò rẹ̀.
2 Fetisilẹ rere, ki ẹ si gbọ́ iró ohùn rẹ̀,
ati iró ti o ti ẹnu rẹ̀ jade wá.
3 O ṣe ilana rẹ̀ nisalẹ abẹ ọrun gbogbo,
manamana rẹ̀ ni o si jọwọ rẹ̀ lọwọ de opin
ilẹ aiye.
4 Lẹhin manamana ohùn kan fọ̀ ramu-
ramu, o fi ohùn ọlanla rẹ̀, sán ãrá: on kì
yio si da ãrá duro nigbati a ba ngbọ́
ohùn rẹ̀.
5 Ọlọrun fi ohùn rẹ̀ sán ãrá iyanilẹnu,
ohun nlanla ni iṣe ti awa kò le imọ̀.
6 Nitoriti o wi fun ojo didì pe, Iwọ rọ̀
silẹ aiye, ati pẹlu fun ọwọ ojo, ati fun ojo
nla agbara rẹ̀.
7 O fi edidi di gbogbo enia, ki gbogbo
wọn ki o le imọ̀ iṣẹ rẹ̀.
8 Nigbana ni awọn ẹranko iwọnu ihò lọ,
nwọn a si wà ni ipò wọn.
9 Lati iha gusu ni ìji ajayika ti ijade
wá, ati otutu lati inu afẹfẹ ti tu awọsanma
ká.
10 Nipa ẹmi Ọlọrun a fi ìdi-omi funni,
ibu-omi a si sunkì.
11 Pẹlupẹlu o fi omi pupọ mu awọsanma
wuwo, a si tú awọsanma imọlẹ rẹ̀ ká.
12 Awọn wọnyi ni a si yi kakiri nipa
ilana rẹ̀, ki nwọn ki o le iṣe ohunkohun
ti o pa fun wọn li aṣẹ loju aiye lori ilẹ.
13 O mu u wá ibãṣe fun ikilọ̀ ni, tabi
fun rere ilẹ rẹ̀, tabi fun ãnu.
14 Jobu dẹtisilẹ si eyi, duro jẹ, ki o si
rò iṣẹ iyanu Ọlọrun.
15 Iwọ mọ̀ akoko ìgba ti Ọlọrun sọ wọn
lọjọ̀, ti o si mu imọlẹ awọsanma rẹ̀ dán.
16 Iwọ mọ̀ ọ̀na ti awọsanma ifo lọ; iṣẹ
iyanu ẹniti o pé ni ìmọ?
17 Aṣọ rẹ̀ ti ma gbona, nigbati o mu
aiye dakẹ lati gusu wá.
18 Iwọ ha ba a tẹ pẹpẹ oju-ọrun, ti o
duro ṣinṣin, ti o si dabi digi ti o yọ́ dà.
19 Kọ́ wa li eyi ti a le iwi fun u; nito-
ripe awa kò le iladi ọ̀rọ nitori òkunkun.
20 A o ha wi fun u pe, Emi fẹ sọrọ?
tabi ẹnikan wipe, Ifẹ mi ni pe ki a gbe mi
mì?
21 Sibẹ nisisiyi enia kò ri imọlẹ ti ndán
ninu awọsanma, ṣugbọn afẹfẹ kọja, a si fẹ
wọn mọ́.
22 Wura didan ti inu iha ariwa jade wá,
lọdọ Ọlọrun li ọlanla ẹ̀ru-nla.
23 Nipa ti Olodumare awa kò le iwadi
rẹ̀ ri, o rekọja ni ipá, on kì iba idajọ ati
ọ̀pọlọpọ otitọ jẹ.
24 Nitorina enia a ma bẹ̀ru rẹ̀, on kì
iṣojusaju ẹnikẹni ti o gbọ́n ni inu.

## ORI 38.

NIGBANA ni OLUWA da Jobu lohùn
lati inu ìji ajayika wá o si wipe,
2 Tani eyi ti nfi ọ̀rọ aini igbiro ṣú ìmọ
li òkunkun.
3 Di ẹgbẹ ara rẹ li amure bi ọkọnrin
nisisiyi, nitoripe emi o bère lọwọ rẹ ki o si
da mi lohùn.
4 Nibo ni iwọ wà nigbati mo fi ipilẹ
aiye sọlẹ? wi bi iwọ ba moye!
5 Tali o fi ìwọn rẹ̀ lelẹ, bi iwọ ba mọ̀,
tabi tani o ta okun wiwọn sori rẹ̀.
6 Lori ibo ni a gbe kan ipilẹ rẹ̀ mọ́, tabi
tali o fi okuta igun rẹ̀ le ilẹ?
7 Nigbati awọn irawọ owurọ jumọ kọrin
pọ̀, ti gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun nhó iho
ayọ̀?
8 Tabi tali o fi ilẹkun sé omi okun mọ́,
nigbati o ya jade bi ẹnipe o ti inu tu jade
wá?
9 Nigbati mo fi awọsanma ṣe aṣọ rẹ̀, ati
òkunkun ṣiṣu ṣe ọ̀ja igbanu rẹ̀?
10 Ti mo ti paṣẹ ipinnu mi fun u, ti mo
si ṣe bèbe ati ilẹkun.
11 Ti mo si wipe, Nihinyi ni iwọ o de,
ki o má si rekọja, nihinyi si ni igberaga
riru omi rẹ yio gbe duro mọ.
12 Iwọ paṣẹ fun owurọ lati igba ọjọ rẹ̀
wá, iwọ si mu ila-õrun mọ̀ ipo rẹ̀?
13 Ki o le idi opin ilẹ aiye mu, ki a le
gbọ̀n awọn ẹnia buburu kuro ninu rẹ̀.
14 Ki o yipada bi amọ fun edidi amọ,
ki gbogbo rẹ̀ ki o si fi ara rẹ̀ hàn bi ẹnipe
ninu aṣọ igunwa.
15 A si fa imọlẹ wọn sẹhin kuro lọdọ
enia buburu, apa giga li o si ṣẹ́.
16 Iwọ ha wọ inu isun okun lọ ri bi?
iwọ si rin lori isalẹ ibú nla?

Digitized by Google

A ha ṣilẹkun ikú silẹ fun ọ ri bi, iwọ
ilẹkun ojiji ikú?
Iwọ̀ moye ibú aiye bi? sọ bi iwọ ba
:bogbo rẹ̀?
Ọna wo ni imọlẹ igbé, bi o ṣe ti
ıkun, nibo ni ipò rẹ̀?
Ti iwọ o fi mu u lọ si ibi àla rẹ̀, ti
ɔ si le imọ̀ ipa-ọ̀na lọ sinu ile rẹ̀?
Iwọ mọ̀ eyi, nitoriti ni igbana ni a
? ati iye ọjọ rẹ si pọ!
Iwọ ha wọ inu iṣura idi-ojo lọ ri bí,
si ri ile iṣura yinyin ri?
Ti mo ti fi pamọ de igba iyọnu, de
ıgun ati ijà.
Ọna wo ni imọlẹ fi nyà, ti afẹfẹ ila-
tàn kakiri lori ilẹ aiye?
Tali o la ipado fun ẹkún iṣan omi,
na fun manamana ãrá?
; Lati mu u rọ̀jo sori aiye, nibiti enia
i, ni aginju nibiti enia kò si.
Lati mu ilẹ tutù, ijù ati alairo, ati
mu irudi ọmọdún eweko ru jade?
Ojo ha ni baba bi, tabi tali o bi ikàn
ri?
Lati inu tani ìdi omi ti jade wá, ati
idi ọrun tali o bi i?
Omi bò o mọlẹ bi ẹnipe labẹ okuta,
.bú nla si dìlupọ̀.
. Iwọ le ifi ọja de awọn irawọ meje
yade] tabi iwọ le itudi irawọ Orionu?
: Iwọ le imu awọn ami mejejila irawọ
ssaroti] jade wá ni igba akoko wọn?
iwọ le iṣe àmọna Arketuru pẹlu awọn
rẹ̀?
3 Iwọ mọ̀ ilana-ilana ọrun, iwọ le ifi
ı rẹ̀ lelẹ li aiye?
4 Iwọ le igbé ohùn rẹ soke de awọ-
na, ki ọ̀pọlọpọ omi ki o le bò ọ?
5 Iwọ le iran mànamána ki nwọn ki o
ọ, ki nwọn ki o si wi fun ọ pe, Awa nĩ!
3 Tali o fi ọgbọ́n si odo-inu, tabi tali
oye sinu aiya?
7 Tali o fi ọgbọ́n ka iye awọsanma, tali
mu igo ọrun dàjade.
3 Nigbati erupẹ di lile, ati ogulutu
?
9 Iwọ o ha dẹ ọdẹ fun abo kiniun bi,
o si tẹ́ ebi ẹgbọrọ kiniun lọrun?
) Nigbati nwọn ba mọlẹ ninu iho wọn,
wọn si ba ni ibuba de ohun ọdẹ.
1 Tani npese ohun jijẹ fun iwo? nigbati
n ọmọ rẹ̀ nkepe Ọlọrun, nwọn a ma fò
nitori aili ohun jijẹ.

## ORI 39.

IWỌ mọ̀ akoko igbati awọn ewurẹ ori apata ibimọ, iwọ si le ikiyesi igba ti abo-agbọnrin ibimọ?
2 Iwọ le ika iye oṣu ti nwọn npé, iwọ si
mọ̀ àkoko igba ti nwọn ibi?
3 Nwọn tẹ ara wọn ba, nwọn bimọ wọn,
nwọn si mu ikãnu wọn jade.
4 Awọn ọmọ wọn ri daradara, nwọn
dagba ninu ọ̀dan, nwọn jade lọ, nwọn kò
si tun pada wá mọ́ sọdọ wọn.
5 Tali o jọ̃ kẹtẹkẹtẹ-oko lọwọ, tabi tali
o tú ide kẹtẹkẹtẹ igbẹ́?
6 Eyi ti mo fi aginju ṣe ile fun, ati ilẹ
iyọ̀ ni ibugbe rẹ̀.
7 O rẹrin si ariwo ilu, bẽni on kò si gbọ́
igbe darandaran.
8 Ori àtòle oke-nla ni ibujẹ oko rẹ̀, on
a si ma wá ewe tutu gbogbo ri.
9 Agbanrere ha jẹ sìn ọ bi, tabi o jẹ
duro ni ibujẹ ẹran rẹ?
10 Iwọ le ifi kátà dè agbanrere ninu
aporo, tabi o jẹ ma fà itulẹ ninu aporo oko
tọ̀ ọ lẹhin?
11 Iwọ o gbẹkẹlẹ e, nitori agbara rẹ̀ pọ̀,
iwọ o si fi iṣẹ rẹ le e li ọwọ?
12 Iwọ le igbẹkẹle e pe, yio mu eso
oko rẹ wá sile; pe, yio si ko o jọ sinu àka
rẹ?
13 Iyẹ abo-ogongo nfi ayọ̀ fì, iyẹ ati
ihuhu rẹ daradara ni bi?
14 Kò ri bẽ? o fi ẹyin rẹ̀ silẹ-yilẹ, a si
mu wọn gbona ninu ekuru.
15 Ti o si gbagbe pe, ẹsẹ le itẹ wọn fọ,
tabi pe, ẹranko igbẹ le itẹ wọn fọ;
16 Kò ni ãjo si awọn ọmọ rẹ̀ bi ẹnipe
nwọn kì iṣe tirẹ̀, asan ni iṣẹ rẹ̀ laibẹru:
17 Nitoripe Ọlọrun dù u li ọgbọ́n, bẽni
kò si fi ipin oye fun u.
18 Nigbati o gbe ara soke, o gàn ẹṣin ati
ẹlẹṣin.
19 Iwọ li o fi agbara fun ẹṣin, iwọ li o fi
gọ̀gọ wọ ọrùn rẹ̀ li aṣọ?
20 Iwọ le imu u fò soke bi ẹlẹnga, ogo
ẽmi imu rẹ̀ ni ẹ̀ru-nla.
21 O fi ẹsẹ halẹ ninu aporo, o si yọ̀ si
agbara rẹ̀; o nlọ jade lati pade awọn aha-
mọra ogun.
22 O fi oju timi wò ẹ̀ru, aiya kò si fò o;
bẽni kì isi ipada sẹhin kuro lọwọ idà.
23 Lọdọ rẹ̀ ni apo-ọfa nmi pẹkẹpẹkẹ, ati
ọ̀kọ didan ati apata.
24 On fi kikoro oju ati ibinu nla gbe ilẹ
mì, bẽli on kò si gbagbọ pe, iro ipè ni
25 O wi ni igba ipè pe, Ha! Ha! o si

Digitized by Google

gborùn ogun lokere rere: ãrá awọn balo-
gun ati ihó àyọ wọn.
26 Awodi a ma ti ipa ọgbọ́n rẹ fò soke,
ti o si nà iyẹ apa rẹ̀ siha gusun ?
27 Idì a ma fi aṣẹ rẹ fò lọ soke, ki o si lọ
itẹ ìtẹ rẹ̀ si oke giga ?
28 O ngbe o si wọ̀ li ori apata, lori pala-
pala okuta ati ibi ori oke.
29 Lati ibẹ lọ ni ima wá ọdẹ kiri, oju rẹ̀
si riran li òkere rere.
30 Awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu a ma mu ẹ̀jẹ, nibi-
ti okú ba gbe wà, nibẹ li on wà pẹlu.

## ORI 40.

OLUWA da Jobu lohùn si i pẹlu, o si
wipe,
2 Ẹniti mba Olodumare jà, yio ha kọ́ ọ
li ẹkọ́ ? ẹniti mba Ọlọrun wi, jẹ ki o
dahùn !
3 Nigbana ni Jobu da Oluwa lohùn, o
si wipe:
4 Kiyesi i, ẹgbin li emi; ohùn kili emi
o da ? emi o fi ọwọ mi le ẹnu mi.
5 Ẹ̃kan ni mo sọ̀rọ̀, ṣugbọn emi kì yio si
tun sọ mọ, lẹ̃meji ni, emi kò si le iṣe e mọ́.
6 Nigbana ni OLUWA da Jobu lohùn lati
inu ìji ajayika wá o si wipe:
7 Di àmure giri li ẹgbẹ rẹ bi ọkọnrin,
emi o bi ọ lere, ki iwọ ki o si kọ́ mi li ẹkọ́.
8 Iwọ ha fẹ imu idajọ mi di asan ? iwọ
o si da mi lẹbi, ki iwọ ki o lẹ iṣe olododo ?
9 Iwọ ni apá bi Ọlọrun, tabi iwọ le ifi
ohùn san ãrá bi on ?
10 Fi ọlanla ati ọla-itayọ ṣe ara rẹ li ọṣọ,
ki o si fi ogo ati ẹwa ọṣọ bò ara rẹ li aṣọ.
11 Mu irunu ibinu rẹ jade, kiyesi gbo-
gbo ìwa igberaga, ki o si rẹ̀ ẹ silẹ.
12 Wò gbogbo ìwa igberaga, ki o si rẹ̀ ẹ
silẹ, ki o si tẹ enia buburu mọlẹ ni ipo wọn.
13 Fi wọn sin pọ̀ ninu erupẹ, ki o si di
oju wọn ni ikọkọ.
14 Nigbana li emi o yìn ọ pe, ọwọ ọ̀tun
ara rẹ le igba ọ la.
15 Njẹ nisisiyi kiyesi Behemotu ti mo
da pẹlu rẹ, on a ma jẹ koriko bi ọ̀da-malu.
16 Wò o nisisiyi, agbara rẹ̀ wà li ẹgbẹ́
rẹ̀, ati ipa rẹ̀ ninu iṣan ikùn rẹ̀.
17 On a ma jù ìru rẹ̀ bi igi kedari, iṣan
itan rẹ̀ dijọ pọ̀.
18 Egungun rẹ̀ ni ogusọ idẹ, egungun rẹ̀
dabi ọpa irin.
19 On ni olu nipa ọ̀na Ọlọrun; ẹniti o
da a o fi idà rẹ̀ le e lọwọ.
20 Nitõtọ oke nlanla ni imu ohun jijẹ
fun u wá, nibiti gbogbo ẹranko igbẹ ima
ṣire.
21 O dubulẹ labẹ igi Lotosi, ninu ifefe
bibò ati ẹrẹ.
22 Igi Lotosi ṣiji wọn bò o, igi arọrọ odò
yi i kakiri.
23 Kiyesi i, odò nla ṣan jọjọ, on kò salọ,
o wà lailewu bi o ba ṣe odò Jordani ti ṣan
lọ si ẹnu rẹ̀.
24 Ẹnikan ha le imu u li oju rẹ̀ tabi a
ma fi ọkọ gun imú rẹ̀ ?

## ORI 41.

IWỌ le ifi ìwọ fa Lefiatani [ọni nla] jade,
tabi iwọ le imu ahọn rẹ̀ ninu okùn ?
2 Iwọ le ifi ìwọ bọ̀ ọ ni imu, tabi o le ifi
ẹgun lu u li ẹrẹkẹ ?
3 On o ha jẹ bẹ ẹ̀bẹ lọdọ rẹ li ọ̀pọlọpọ
bi, on o ha ba ọ sọ̀rọ pẹlẹ ?
4 On o ha ba ọ dá mejẹmu bi, iwọ o ha
ma mu u ṣe iranṣẹ lailai bi ?
5 Iwọ ha le ba a ṣire bi ẹnipe ẹiyẹ ni,
tabi iwọ o dè e fun awọn ọmọbirin iranṣẹ
rẹ ?
6 Ẹgbẹ awọn apẹja yio ha ma tà a bi,
nwọn o ha pin i lãrin awọn oniṣowo ?
7 Iwọ le isọ awọ rẹ̀ kun fun irin abeti,
tabi iwọ o sọ ori rẹ̀ kún fun ẹṣín apẹja.
8 Fi ọwọ rẹ le e lara, iwọ o ranti ìja na,
iwọ kì yio ṣe bẹ̃ mọ.
9 Kiyesi i, abá nipasẹ rẹ̀ ni asan, ni kìki
ìri rẹ̀ ara kì yio ha rọ̀ ọ wẹsi ?
10 Kò si ẹni-alaiya lile ti o le iru u so-
ke; njẹ tali o le duro niwaju rẹ̀ ?
11 Tani o ṣaju ṣe fun mi, ti emi iba fi
san fun u ? ohunkohun ti mbẹ labẹ ọrun
gbogbo ti emi ni.
12 Emi kì yio fi ipin ara rẹ̀ pamọ, tabi
ipá rẹ̀, tabi ihamọra rẹ̀ ti o li ẹwà.
13 Tani yio le iridi oju aṣọ apata rẹ̀, tabi
tani o le isunmọ ọ̀na meji ehin rẹ̀.
14 Tani o le iṣi ilẹkun iwaju rẹ̀ ? ayika
ehin rẹ̀ ni ìbẹru nla.
15 Ipẹ lile ni igberaga rẹ̀, o pade pọ
mọtimọti bi ami edidi,
16 Ekini fi ara mọ ekeji tobẹ̃ ti afẹfẹ kò
lẹ iwọ̀ arin wọn.
17 Ekini fi ara mọra ekeji rẹ̀, nwọn lẹmọ
pọ̀ ti a kò le iyà wọn.
18 Nipa sísin rẹ̀ imọlẹ a mọ́, oju rẹ̀ a si
dabi ipénpeju owurọ.
19 Lati ẹnu rẹ̀ ni ọwọ́-iná ti ijade wá,
ipẹpẹ iná a si ta jade.
20 Lati iho-imú rẹ̀ li ẹfin ti ijade wa, bi
ẹnipe lati inu ikoko ti a fẹ́ iná ifefe labẹ rẹ̀.
21 Ẹmi rẹ̀ tinabọ ẹyin, ọ̀wọ-iná si ti ẹnu
rẹ̀ jade.

Digitized by Google

22 Li ọrùn rẹ̀ li agbara kù si, ati ibinujẹ
aiya si pada di ayọ̀ niwaju rẹ̀.
23 Jabajaba ẹran rẹ̀ dijọ pọ̀, nwọn mura
giri fun ara wọn, a kò le iṣi wọn ni ipò.
24 Aiya rẹ̀ duro gbagigbagi bi okuta,
ani o le bi iya-ọlọ.
25 Nigbati o ba gbe ara rẹ̀ soke, awọn
alagbara a bẹ̀ru, nitori ìbẹru nla, nwọn
damu.
26 Idá ẹniti o ṣa a kò le iràn a, ọ̀kọ,
ẹṣin tabi ọfa.
27 O ka irin si bi koriko gbigbẹ, ati idẹ
si bi igi hihù.
28 Ọfa kò le imu u sá, okuta kànakana
lọdọ rẹ̀ dabi akeku koriko.
29 O ka ẹṣin si bi akeku idi koriko, o
rẹrin si ìmisi ọ̀kọ.
30 Okuta mimú mbẹ nisalẹ abẹ rẹ̀, o si
tẹ̀ ohun mimú ṣonṣo sori ẹrẹ.
31 O mu ibu omi hó bi ìkoko, o sọ
agbami okun dabi ẹ̀ba.
32 O mu ipa-ọ̀na tàn lẹhin rẹ̀, enia a ma
ka ibu si ewú arugbo.
33 Lori ilẹ aiye kò si iru rẹ̀, ti a da laini
ìbẹru.
34 O bojuwo ohun giga gbogbo, o si ni-
kan jasi ọba lori gbogbo awọn ọmọ-igbe-
raga.

## ORI 42.

NIGBANA ni Jobu da OLUWA lohùn o si
wipe,
2 Emi mọ̀ pe, iwọ le iṣe ohun gbogbo,
ati pe, kò si iro-inu ti a le ifasẹhin kuro
lọdọ rẹ.
3 Tani ẹniti nfi ìgbimọ pamọ laini imọ ?
nitorina ni emi ṣe nsọ eyi ti emi kò mọ̀,
ohun ti o ṣe iyanu jọjọ niwaju mi, ti emi
kò moye.
4 Emi bẹ̀ ọ, gbọ́, emi o si sọ, emi o bère
lọwọ rẹ, ki iwọ ki o si bùn mi ni oye.
5 Emi ti fi gbigbọ́ eti gburo rẹ, ṣugbọn
nisisiyi oju mi ti ri ọ.
6 Njẹ nitorina emi korira ara mi, mo si
ronupiwada ṣe tóto ninu ekuru ati ẽru.
7 Bẹ̃li o si ri, lẹhin igbati OLUWA ti sọ
ọ̀rọ wọnyi tan fun Jobu, OLUWA si wi fun
Elifasi, ara Tema pe, Mo binu si ọ ati si
awọn ọrẹ́ rẹ mejeji, nitoripe ẹnyin kò sọ̀rọ
niti emi, ohun ti o tọ́ bi Jobu iranṣẹ mi
ti sọ.
8 Nitorina ẹ mu akọ ẹgbọrọ malu meje,
ati àgbo meje, ki ẹ si tọ̀ Jobu iranṣẹ mi lọ,
ki ẹ si fi rú ẹbọ sisun fun ara nyin : Jobu
iranṣẹ mi yio si gbadura fun nyin : nitori-
pe oju rẹ̀ ni mo gbà ; ki emi ki o má ba ṣe
si nyin bi iṣina nyin, niti ẹnyin kò sọ̀rọ
ohun ti o tọ́ si mi bi Jobu iranṣẹ mi.
9 Bẹ̃ni Elifasi, ara Tema, ati Bildadi,
ara Ṣua, ati Sofari, ara Naama lọ, nwọn si
ṣe gẹgẹ bi OLUWA ti paṣẹ fun wọn : OLUWA
si gbà oju Jobu.
10 OLUWA si yi igbekun Jobu pada, ni-
gbati o gbadura fun awọn ọrẹ rẹ̀ : OLUWA
si busi ohun gbogbo ti Jobu ni rí ni iṣẹpo
meji.
11 Nigbana ni gbogbo awọn arakọnrin
rẹ̀, ati gbogbo awọn arabirin rẹ̀, ati gbogbo
awọn ti o ti ṣe ojulumọ rẹ̀ rí, nwọn mba a
jẹun ninu ile rẹ̀, nwọn si ṣe idaro rẹ̀, nwọn
si ṣipẹ fũn nitori ibi gbogbo ti OLUWA ti
mu ba a : olukuluku enia pẹlu si bùn u ni
ike owo-kọkan ati olukuluku ni oruka
wura eti kõkan.
12 Bẹ̃li OLUWA bukún igbẹhin Jobu jù
iṣaju rẹ̀ lọ ; o si ni ẹgba-meje agutan, ẹgba-
mẹta ibakasiẹ, ati ẹgbẹrun ajaga ọda-malu,
ati ẹgbẹrun abo kẹtẹkẹtẹ.
13 O si ni ọmọkọnrin meje ati ọmọbirin
mẹta.
14 O si sọ orukọ akọbi ni Jemima, ati
orukọ ekeji ni Kesia, ati orukọ ẹkẹta ni
Keren-happuki.
15 Ati ni gbogbo ilẹ na, a kò ri obirin
ti o li ẹwa bi ọmọbirin Jobu ; baba wọn si
pinlẹ fun wọn ninu awọn arakọnrin wọn.
16 Lẹhin eyi Jobu wà li aiye li ogoje
ọdun, o si ri awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin ati awọn
ọmọ-ọmọ rẹ̀ ọkọnrin, ani iran mẹrin.
17 Bẹ̃ni Jobu kú, o gbó, o si kún fun
ọjọ.

Digitized by Google

# ORIN DAFIDI.

## IWE I.

### ORIN 1.

IBUKÚN ni fun ọkọnrin na ti kò rìn ni ìmọ awọn enia buburu, ti kò duro li ọ̀na awọn ẹlẹṣẹ, ati ti kò si joko ni ibujoko awọn ẹlẹgàn.

2 Ṣugbọn didùn-inu rẹ̀ wà li ofin Oluwa; ati ninu ofin rẹ̀ li o nṣe aṣaro li ọsan ati li oru.

3 Yio si dabi igi ti a gbìn si eti ipa odò, ti nso eso rẹ̀ jade li akokò rẹ̀; ewe rẹ̀ kì yio si rẹ̀; ati ohunkohun ti o ṣe ni yio ma ṣe dede.

4 Awọn enia buburu kò ri bẹ̃: ṣugbọn nwọn dabi iyangbo ti afẹfẹ nfẹ lọ.

5 Nitorina awọn enia buburu kì yio dide duro ni idajọ, bẹ̃li awọn ẹlẹṣẹ kì yio le duro li awujọ awọn olododo.

6 Nitori Oluwa mọ̀ ọ̀na awọn olododo: ṣugbọn ọ̀na awọn enia buburu ni yio ṣegbe.

### ORIN 2.

ẼṢE ti awọn orilẹ-ède fi nbinu fùfu, ati ti awọn enia ngbiro ohun asan?

2 Awọn ọba aiye kẹsẹ jọ, ati awọn ijoye ngbimọ pọ̀ si Oluwa ati si Ẹni-ororo rẹ̀ pe,

3 Ẹ jẹ ki a fa ìde wọn já, ki a si mu okùn wọn kuro li ọdọ wa.

4 Ẹniti o joko li ọrun yio rẹrin: Oluwa yio yọ ṣùti si wọn.

5 Nigbana ni yio sọ̀rọ si wọn ni ibinu rẹ̀, yio si yọ wọn lẹnu ninu ibinujẹ rẹ̀ kikan.

6 Ṣugbọn mo ti fi Ọba mi jẹ lori Sioni, òke mimọ́ mi.

7 Emi o si rohin ipinnu Oluwa: O ti wi fun mi pe, Iwọ li Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ.

8 Bère lọwọ mi, emi o si fi awọn orilẹ-ède fun ọ ni ini rẹ, ati iha opin ilẹ li ọrọ̀-ilẹ rẹ.

9 Ọpá irin ni iwọ o fi fọ́ wọn; iwọ o si run wọn wom-wom, bi ohun-elo amọ̀.

10 Njẹ nitorina ki ẹnyin ki o gbọ́n, ẹnyin ọba: ki a si kọ́ nyin, ẹnyin onidajọ aiye.

11 Ẹ fi ìbẹru sìn Oluwa, ẹ si ma yọ̀ ti ẹnyin ti iwariri.

12 Fi ẹnu kò Ọmọ na lẹnu, ki o máṣe binu, ẹnyin a si ṣegbe li ọ̀na na, bi inu rẹ̀ ba ru diẹ kiun. Ibukún ni fun gbogbo awọn ti o gbẹkẹ wọn le e.

### ORIN 3.

*Orin Dafidi nigbati o salọ niwaju Absalomu, ọmọ rẹ̀.*

OLUWA, awọn ti nyọ mi li ẹnu ti npọ̀ to yi! ọ̀pọlọpọ li awọn ti o dide si mi.

2 Ọpọlọpọ li awọn ti o nwi niti ọkàn mi pe, Iranlọwọ kò si fun u nipa ti Ọlọrun.

3 Ṣugbọn iwọ, Oluwa, li asà fun mi; ogo mi; ati olugbe ori mi soke.

4 Emi fi ohùn mi kigbe si Oluwa, o si gbohùn mi lati òke mimọ́ rẹ̀ wá.

5 Emi dubulẹ, mo si sùn; mo si ji; nitori ti Oluwa tì mi lẹhin,

6 Emi kì yio bẹ̀ru ọ̀pọlọpọ enia, ti nwọn rọ̀gba yi mi ka.

7 Dide Oluwa; gbà mi, Ọlọrun mi: nitori iwọ li o lù gbogbo awọn ọta mi li egungun ẹrẹkẹ; iwọ si ká ehin awọn enia buburu.

8 Ti Oluwa ni igbala: ibukún rẹ si mbẹ lara awọn enia rẹ.

### ORIN 4.

GBOHÙN mi nigbati mo ba npè, Ọlọrun ododo mi: iwọ li o da mi ni ìde ninu ipọnju; ṣe ojurere fun mi, ki o si gbọ́ adura mi.

2 Ẹnyin ọmọ enia, ẹ o ti sọ ogo mi di itiju pẹ to? ẹnyin o ti fẹ asan pẹ to, ti ẹ o si ma wá eke iṣe?

3 Ṣugbọn ki ẹ mọ̀ pe Oluwa yà ẹni ayanfẹ sọ̀tọ fun ara rẹ̀: Oluwa yio gbọ́ nigbati mo ba kepè e.

4 Ẹ duro ninu ẹ̀ru, ẹ má si ṣe ṣẹ̀; ẹ ba ọkàn nyin sọ̀rọ lori ẹní nyin, ki ẹ si duro jẹ.

5 Ẹ ru ẹbọ ododo, ki ẹ si gbẹkẹ nyin le Oluwa.

Digitized by Google

Ẹni pupọ li o nwipe, Tani yio ṣe rere
wa? Oluwa, iwọ gbé imọlẹ oju rẹ soke
 lara.
Iwọ ti fi ayọ̀ si mi ni inu, jù igba na
ọkà wọn ati ọti-waini wọn di pupọ̀.
Emi o dubulẹ pẹlu li alafia, emi o si
 nitori iwọ, Oluwa, nikanṣoṣo li o
mi joko li ailewu.

ORIN 5.

eti si ọ̀rọ mi, Oluwa, kiyesi aroye mi.
2 Fi eti si ohùn ẹkún mi, Ọba mi, ati
un mi: nitoripe ọdọ rẹ li emi o ma
ura si.
Ohùn mi ni iwọ o gbọ́ li owurọ, Oluwa,
urọ li emi o gbà adura mi si ọ, emi o
a wòke.
Nitori ti iwọ kì iṣe Ọlọrun ti iṣe inu-
n si ìwa buburu: bẽni ibi kò le ba ọ

Awọn agberaga kì yio le duro niwaju
iwọ korira gbogbo awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ.
Iwọ o pa awọn ti nṣe eke run; Oluwa
orira awọn ẹni-ẹ̀jẹ, ati ẹni-ẹ̀tan.
Ṣugbọn bi o ṣe ti emi, emi o wá sinu
 li ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ: ninu ẹ̀ru rẹ li emi
iba si iha tempili mimọ́ rẹ.
Tọ́ mi, Oluwa, ninu ododo rẹ, nitori
 ọta mi: mu ọ̀na rẹ tọ́ tàra niwaju

Nitori ti otitọ kan kò si li ẹnu ẹnikẹni
; ikakika ni iha inu wọn; isa-okú ti
silẹ li ọfun wọn; ahọn wọn ni nwọn fi
ni.
) Iwọ da wọn lẹbi, Ọlọrun; ki nwọn
 ti ipa ìmọ ara wọn ṣubu; já wọn kuro
ri ọ̀pọlọpọ irekọja wọn; nitori ti nwọn
tẹ si ọ.
 Nigbana ni gbogbo awọn ti ngbẹkẹle
o yọ̀; lai nwọn o ma ho fun ayọ, nito-
iwọ dabobo wọn: ati awọn ti o fẹ
ọ rẹ pẹlu yiọ ma yọ̀ ninu rẹ.
2 Nitori iwọ, Oluwa, ni yio bukún u
olododo; oju-rere ni iwọ o fi yi i ka bi

ORIN 6.

UWA, máṣe ba mi wi ni ibinu rẹ, ki
 iwọ ki o má ṣe nà mi ni gbigbona ibi-
 rẹ.
Oluwa, ṣãnu fun mi; nitori ailera mi:
wa, mu mi lara da; nitori ti ara kan
ngun mi.
Ara kan ọkàn mi gogo pẹlu: ṣugbọn
, Oluwa, yio ti pẹ to!

4 Pada, Oluwa, gbà ọkàn mi: gbà mi
là nitori ãnu rẹ.
5 Nitoriti kò si iranti rẹ ninu okú: ninu
isa okú tani yio dupẹ fun ọ?
6 Agara ikerora mi da mi: li oru gbogbo
li emi nmu ẹní mi fó li oju omi; emi fi
omije mi rin ibusùn mi.
7 Oju mi bajẹ tan nitori ibinujẹ; o di
ogbó tan nitori gbogbo awọn ọta mi.
8 Ẹ lọ kuro lọdọ mi, gbogbo ẹnyin
oniṣẹ ẹ̀ṣẹ; nitori ti Oluwa gbọ́ ohùn ẹkún
mi.
9 Oluwa gbọ́ ẹ̀bẹ mi; Oluwa yio gbà
adura mi.
10 Oju yio tì gbogbo awọn ọta mi, ara
yio sì kan wọn gogo: nwọn o pada, oju
yio tì wọn lojiji.

ORIN 7.

*Orin Dafidi ti o kọ si Oluwa niti ọ̀ran Kuṣi, ọmọ Benjamini.*

OLUWA, Ọlọrun mi, iwọ ni mo gbẹkẹ
mi le: gbà mi lọwọ gbogbo awọn ti
nṣe inunibini si mi, ki o si yọ mi kuro.
2 Ki o má ba fa ọkàn mi ya bi kiniun, a
yà a pẹrẹpẹrẹ, nigbati kò si oluranlọwọ.
3 Oluwa, Ọlọrun mi, bi mo ba ṣe eyi, bi
ẹ̀ṣẹ ba mbẹ li ọwọ mi;
4 Bi mo ba fi ibi san a fun ẹniti temi
tirẹ̀ wà li alafia; (nitõtọ ẹniti nṣe ọta mi li
ainidi, emi tilẹ gbà a là:)
5 Jẹ ki ọta ki o ṣe inunibini si ọkàn mi,
ki o si mu u; ki o tẹ̀ ẹmi mi mọlẹ, ki o si
fi ọlá mi le inu ekuru.
6 Dide Oluwa, ni ibinu rẹ! gbé ara rẹ
soke nitori ikannu awọn ọta mi: ki iwọ
ki o si jí fun mi si idajọ ti iwọ ti pa li
aṣẹ.
7 Bẽni ijọ awọn enia yio yi ọ ká kiri;
njẹ nitori wọn iwọ pada si òke.
8 Oluwa yio ṣe idajọ awọn enia: Oluwa
ṣe idajọ mi, gẹgẹ bi ododo mi, ati gẹgẹ bi
ìwatitọ inu mi.
9 Jẹ ki ìwa-buburu awọn enia buburu ki
o de opin: ṣugbọn mu olotitọ duro: ni-
toriti Ọlọrun olododo li o ndan aiya ati
inu wò.
10 Abo mi mbẹ lọdọ Ọlọrun ti o nṣe
igbala olotitọ li aiya.
11 Ọlọrun li onidajọ ododo, Ọlọrun si
nbinu si enia buburu lojojumọ:
12 Bi on kò ba yipada, yio si pọ́n idà
rẹ̀ mu: o ti fà ọrun rẹ̀ le na, o ti mura rẹ̀
silẹ.
13 O si ti pèse elo ikú silẹ fun u; o ti
ṣe awọn ọfa rẹ̀ ni oniná.



Digitized by Google

14 Kiyesi i, o nrọbi ẹ̀ṣẹ, o si loyun ìwa-
ìka, o si bí eké jade.
15 O ti wà ọ̀fin, o gbẹ́ ẹ, o si bọ́ sinu iho
ti on na wà.
16 Iwa-ika rẹ̀ yio si pada si ori ara rẹ̀,
ati ìwa-agbara rẹ̀ yio si sọ̀kalẹ bọ̀ si atari
ara rẹ̀.
17 Emi o yìn Oluwa gẹgẹ bi ododo rẹ̀:
emi o si kọrin iyìn si orukọ Oluwa Ọga-ogo
julọ.

## ORIN 8.

OLUWA, Oluwa wa, orukọ rẹ ti ni iyìn
to ni gbogbo aiye! iwọ ti o gbé ogo rẹ
kà ori awọn ọrun.
2 Lati ẹnu awọn ọmọ-ọwọ ati ọmọ-ọmu
ni iwọ ti ṣe ilana agbara, nitori awọn ọta
rẹ, nitori ki iwọ ki o le mu ọta olugbẹsan
ni dakẹjẹ.
3 Nigbati mo rò ọrun rẹ, iṣẹ ika rẹ,
oṣupa ati irawọ, ti iwọ ti ṣe ilana silẹ.
4 Kili enia, ti iwọ fi nṣe iranti rẹ̀? ati
ọmọ enia, ti iwọ fi mbẹ̀ ẹ wò.
5 Iwọ sa da a li onirẹlẹ diẹ jù Ọlọrun lọ,
iwọ si ti fi ogo ati ọlá de e li ade.
6 Iwọ mu u jọba iṣẹ ọwọ rẹ; iwọ si ti fi
ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ rẹ̀;
7 Awọn agutan ati awọn malu pẹlu, ati
awọn ẹranko igbẹ;
8 Awọn ẹiyẹ oju ọrun, ati awọn ẹja
ọkun, ti o nkọja lọ nipa ọ̀na okun.
9 Oluwa, Oluwa wa, orukọ rẹ ti ni iyìn
to ni gbogbo aiye!

## ORIN 9.

EMI o fi gbogbo aiya mi yìn Oluwa: emi
o fi gbogbo iṣẹ iyanu rẹ hàn.
2 Emi o yọ̀, emi o si ṣe inu-didùn ninu
rẹ, emi o si kọrin iyìn si orukọ rẹ, iwọ
Ọga-ogo julọ.
3 Nigbati awọn ọta mi ba pẹhinda, nwọn
o ṣubu, nwọn o si ṣegbe ni iwaju rẹ.
4 Nitori iwọ li o ti mu idajọ mi ati idi
ọ̀ran mi duro; iwọ li o joko lori itẹ́, ti o
nṣe idajọ ododo.
5 Iwọ ba awọn orilẹ-ède wi, iwọ pa awọn
enia buburu run, iwọ pa orukọ wọn rẹ́ lai
ati lailai.
6 Niti ọta, iparun wọn pari tan lailai:
iwọ li o si ti run ilu wọnni; iranti wọn si
ti ṣegbe pẹlu wọn.
7 Ṣugbọn Oluwa yio wà titi lailai: o ti
tẹ́ itẹ́ rẹ̀ silẹ fun idajọ.
8 On o si ṣe idajọ aiye li ododo, yio ṣe
idajọ fun awọn enia li otitọ ìwa.
9 Oluwa ni yio ṣe àbo awọn ẹni inilara,
àbo ni igba ipọnju.
10 Awọn ti o si mọ̀ orukọ rẹ o gbẹkẹ le
ọ: nitori iwọ, Oluwa, kò ti ikọ̀ awọn ti nṣe
afẹri rẹ silẹ.
11 Ẹ kọrin iyìn si Oluwa, ti o joko ni
Sioni: ẹ fi iṣẹ rẹ̀ hàn ninu awọn enia.
12 Nigbati o wadi ẹjọ-ẹ̀jẹ, o ranti wọn:
on kò si gbagbe ẹkún awọn olupọnju.
13 Ṣãnu fun mi, Oluwa; rò iṣẹ́ ti emi
nṣẹ́ lọwọ awọn ti o korira mi, iwọ ti o gbé
ori mi soke kuro li ẹnu-ọ̀na ikú.
14 Ki emi ki o le ma fi gbogbo iyìn rẹ
hàn li ẹnu-ọ̀na ọmọbirin Sioni, emi o ma
yọ̀ ni igbala rẹ.
15 Awọn orilẹ-ède jìn sinu ọ̀fin ti nwọn
wà: ninu àwọn ti nwọn dẹ silẹ li ẹsẹ ara
wọn kọ́.
16 A mọ̀ Oluwa, nipa idajọ ti o nṣe:
nipa iṣẹ ọwọ enia buburu li a fi ndẹkùn
mu u.
17 Ori awọn enia buburu li a o dà si
ọrun apadi, ati gbogbo orilẹ-ède ti o gbagbe
Ọlọrun.
18 Nitori pe a kì yio gbagbe awọn alai-
ni lailai: abá awọn talaka kì yio ṣegbe
lailai.
19 Oluwa, dide; máṣe jẹ ki enia ki o
bori: jẹ ki a ṣe idajọ awọn orilẹ-ède niwaju
rẹ.
20 Dẹru ba wọn, Oluwa: ki awọn orilẹ-
ède ki o le mọ̀ ara wọn pe, enia ṣa ni
nwọn.

## ORIN 10.

EṢE ti iwọ fi duro li òkere rere, Oluwa;
ẽṣe ti iwọ fi fi ara pamọ́ ni igba
ipọnju.
2 Ninu igberaga li enia buburu nṣe inu-
nibini si awọn talaka: ninu arekereke ti
nwọn rò ni ki a ti mu wọn.
3 Nitori enia buburu nṣogo ifẹ ọkàn rẹ̀,
o si nsure fun olojukokoro, o si nkẹgan
Oluwa.
4 Enia buburu, nipa igberaga oju rẹ̀, kò
fẹ ṣe afẹri Ọlọrun: Ọlọrun kò si ni gbogbo
ironu rẹ̀.
5 Ọ̀na rẹ̀ nlọ siwaju nigbagbogbo; idajọ
rẹ jina rere kuro li oju rẹ̀; gbogbo awọn
ọta rẹ̀ li o nfẹ̀ si.
6 O ti wi li ọkàn rẹ̀ pe, A kì yio ṣi mi
ni ipò: lati irandiran emi kì yio si ninu
ipọnju.
7 Ẹnu rẹ̀ kún fun egún, ati fun ẹ̀tan,
ati fun itanjẹ: ìwa-ìka ati ìwa-asan mbẹ
labẹ ahọn rẹ̀.

Digitized by Google

8 O joko ni buba ni ileto wọnni: ni ibi
ọkọ wọnni li o npa awọn alaiṣẹ̀: oju rẹ̀
ọ awọn talaka nikọkọ.
9 O lùmọ ni ibi ìkọkọ bi kiniun ninu
ntiri: o lùmọ lati mu talaka: a si mu
aka, nigbati o ba fà a sinu àwọn rẹ̀.
10 O ba, o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, ki talaka ki o
bọ́ si ọwọ agbara rẹ̀.
11 O ti wi li ọkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun ti
ıgbe: o pa oju rẹ̀ mọ́; on kì yio ri i
lai.
12 Dide, Oluwa; Ọlọrun, gbé ọwọ rẹ
ɛe: máṣe gbagbe olupọnju.
13 Ẽṣe ti enia buburu fi ngàn Ọlọrun?
ri li ọkàn rẹ̀ pe, Iwọ kì yio bère.
14 Iwọ ti ri i; nitori iwọ nwò ìwa-ìka
iwọsi, lati fi ọ̀ran na le ọwọ rẹ; talaka
ara rẹ̀ le ọ lọwọ; iwọ li oluranlọwọ
ini-baba.
15 Ṣẹ́ apa enia buburu, ati ti ọkọnrin
nì: iwọ wá ìwa-buburu rẹ̀ ri, titi iwọ
yio fi ri i mọ́.
16 Oluwa li ọba lai ati lailai: awọn ke-
i run kuro ni ilẹ rẹ̀.
.7 Oluwa, iwọ ti gbọ́ ifẹ onirẹlẹ: iwọ o
. ọkàn wọn duro, iwọ o dẹ eti rẹ si i.
.8 Lati ṣe idajọ alaini-baba ati ẹni-ini-
ı, ki ọkọnrin aiye ki o máṣe daiyafo-ni
.

## ORIN 11.

LUWA ni mo gbẹkẹ mi le: ẹ ha ti ṣe
wi fun ọkàn mi pe, sá bi ẹiyẹ lọ si òke
n?
: Sa kiyesi i, awọn enia buburu ti fà
n wọn le, nwọn ti fi ọfa sùn li oju ọṣán,
awọn ki o le ta a li òkunkun si ọlọkàn
uro.
: Bi ipilẹ ba bajẹ, kili olododo yio ṣe?
: Oluwa mbẹ ninu tempili mimọ́ rẹ̀, itẹ́
ıwa mbẹ li ọrun: oju rẹ̀ nwò, ipenpeju
ıdán awọn ọmọ enia wò.
· Oluwa ndán olododo wò: ṣugbọn enia
ouru ati ẹniti nfẹ ìwa-agbara, ọkàn rẹ̀
ira.
: Lori enia buburu ni yio rọjo, ẹyín
gbona ati imi-ọjọ ati iji gbigbona: eyi
pin ago wọn.
Nitori olododo li Oluwa, o fẹ ododo;
ọn ẹniti o duro-ṣinṣin yio ri oju rẹ̀.

## ORIN 12

BA-NI Oluwa; nitori awọn ẹni ìwabi-
ọlọrun dasẹ̀; nitori awọn olõtọ dasẹ̀
o ninu awọn ọmọ enia.
Olukuluku wọn mba ẹnikeji rẹ̀ sọ
asan; ète ipọnni ati ọkàn meji ni nwọn fi
nsọ.
3 Oluwa yio ké gbogbo ète ipọnni kuro,
ati ahọn ti nsọ̀rọ ohun nla.
4 Ti o wipe, Ahọn wa li awa o fi ṣẹgun;
ète wa ni ti wa: tani iṣe oluwa wa?
5 Nitori inira awọn talaka, nitori imi-
ẹ̀dun awọn alaini, Oluwa wipe, nigbayi li
emi o dide; emi o si yọ ọ si ibi ailewu
kuro lọwọ ẹniti nfẹ̀ si i.
6 Ọ̀rọ Oluwa, ọ̀rọ funfun ni, bi fadaka ti
a yọ́ ni ileru erupẹ, ti a dà ni igba meje.
7 Iwọ o pa wọn mọ́, Oluwa, iwọ o pa
olukuluku wọn mọ́ kuro lọwọ iran yi lailai.
8 Awọn enia buburu nrìn ni iha gbogbo,
nigbati a ba gbé awọn enia-kenia leke.

## ORIN 13.

IWỌ o ti gbagbe mi pẹ to, Oluwa, lailai?
iwọ o ti pa oju rẹ mọ́ pẹ to kuro lara
mi?
2 Emi o ti ma gbìmọ li ọkàn mi pẹ to?
ti emi o ma ni ibinujẹ li ọkàn mi lojo-
jumọ? ọta mi yio ti gberaga sori mi pẹ to?
3 Rò o, ki o si gbohùn mi, Oluwa Ọlọrun
mi: mu oju mi mọlẹ, ki emi ki o má ba
sùn orun ikú.
4 Ki ọta mi ki o má ba wipe, emi ti
ṣẹgun rẹ̀; awọn ti nyọ mi lẹnu a si ma yọ̀,
nigbati a ba ṣi mi nipò.
5 Ṣugbọn emi o gbẹkẹle ãnu rẹ; ọkàn
mi yio yọ̀ ni igbala rẹ.
6 Emi o ma kọrin si Oluwa, nitoriti o ṣe
fun mi li ọ̀pọlọpọ.

## ORIN 14.

AṢIWERE wi li ọkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun kò si.
Nwọn bajẹ, nwọn si nṣe iṣẹ irira, kò
si ẹniti nṣe rere.
2 Oluwa bojuwò lati ọrun wá sara awọn
ọmọ enia, lati wò bi ẹnikan wà ti oye ye,
ti o si nwá Ọlọrun.
3 Gbogbo wọn li o si jumọ yà si apakan,
nwọn si di elẽri patapata; kò si ẹniti nṣe
rere, kò si ẹnikan.
4 Gbogbo awọn ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ kò ha ni
ìmọ? awọn ẹniti njẹ enia mi bi ẹni jẹun,
nwọn kò si kepè Oluwa.
5 Nibẹ ni ẹ̀ru bà wọn gidigidi: nitoriti
Ọlọrun mbẹ ninu iran olododo.
6 Ẹnyin dojutì ìmọ awọn talaka, ṣugbọn
Oluwa li àbo rẹ̀.
7 Tani yio fi igbala fun Israeli lati Sion?
jade wá! nigbati Oluwa ba mu ikólọ awọn
enia rẹ̀ pada bọ̀, Jakobu yio yọ̀, inu Israeli
yio si dùn.

Digitized by Google

## ORIN 15.

OLUWA, tani yio ma ṣe atipo ninu agọ
rẹ? tani yio ma gbe inu òke mimọ́
rẹ?
2 Ẹniti o nrìn dede, ti nṣiṣẹ ododo, ti o
si nsọ otitọ inu rẹ̀.
3 Ẹniti kò fi ahọn rẹ̀ sọ̀rọ ẹni lẹhin, ti
kò si ṣe ibi si ẹnikeji rẹ̀, ti kò si gbà ọ̀rọ
ẹ̀gan si ẹnikeji rẹ̀.
4 Li oju ẹniti enia-kenia di gigàn;
ṣugbọn a ma bu ọla fun awọn ti o bẹ̀ru
Oluwa. Ẹniti o bura si ibi ara rẹ̀, ti kò si
yipada.
5 Ẹniti kò fi owo rẹ̀ gbà èle, ti kò si gbà
owo ẹ̀bẹ si alaiṣẹ. Ẹniti o ba ṣe nkan
wọnyi kì yio yẹsẹ lailai.

## ORIN 16.

OLỌRUN, pa mi mọ́: nitori iwọ ni mo
gbẹkẹ mi le.
2 Ọkàn mi, iwọ ti wi fun Oluwa pe, Iwọ
li Oluwa mi: emi kò ni ire kan lẹhin rẹ.
3 Si awọn enia mimọ́ ti o wà li aiye, ani
si awọn ọlọla, lara ẹniti didùn inu mi gbo-
gbo gbe wà.
4 Ibinujẹ awọn ti nsare tọ̀ ọlọrun miran
lẹhin yio pọ̀: ẹbọ ohun mimu ẹ̀jẹ wọn li
emi kì yio ta silẹ, bẽli emi kì yio da orukọ
wọn li ẹnu mi.
5 Oluwa ni ipin ini mi, ati ti ago mi:
iwọ li o mu ìla mi duro.
6 Okùn tita bọ́ sọdọ mi ni ibi daradara;
lõtọ, emi ni ogún rere.
7 Emi o fi ibukún fun Oluwa, ẹniti o ti
nfun mi ni ìmọ; ọkàn mi pẹlu nkọ́ mi ni
wakati oru.
8 Emi ti gbé Oluwa kà iwaju mi nigba-
gbogbo; nitori o wà li ọwọ ọtún mi, a kì
yio ṣi mi ni ipò.
9 Nitorina ni inu mi ṣe dùn, ti ogo mi
si nyọ̀; ara mi pẹlu yio simi ni ireti.
10 Nitori iwọ kì yio fi ọkàn mi silẹ ni
ipò-okú; bẽni iwọ kì yio jẹ ki Ẹni Mimọ́
rẹ ki o ri idibajẹ.
11 Iwọ o fi ipa ọ̀na ìye hàn mi; ni iwaju
rẹ li ẹkún ayọ̀ wà: li ọwọ ọtún rẹ ni didùn-
inu wà lailai.

## ORIN 17.

GBỌ́ otitọ, Oluwa, fiyesi igbe mi, fi eti si
adura mi, ti kò ti ète ẹ̀tan jade.
2 Jẹ ki idajọ mi ki o ma ti iwaju rẹ jade
wá: jẹ ki oju rẹ ki o ma wò ohun ti o ṣe
ẹ̃de.
3 Iwọ ti dan aiya mi wò; iwọ ti bẹ̀ ẹ wò
li oru; iwọ ti wadi mi, iwọ kò ri nkan;
emi ti pinnu rẹ̀ pe, ẹnu mi kì yio ṣẹ̀.
4 Niti iṣẹ enia, nipa ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ emi ti pa
ara mi mọ́ kuro ni ipa alaparun.
5 Fi ìrin mi le ilẹ ni ipa rẹ, ki atẹlẹ ẹsẹ
mi ki o máṣe yẹ̀.
6 Emi ti nkepè ọ, nitori pe iwọ o gbo-
hùn mi, Ọlọrun: dẹ eti rẹ si mi, ki o si
gbọ́ ọ̀rọ mi:
7 Fi iṣeun ifẹ iyanu rẹ hàn, iwọ ti o fi
ọwọ ọtún rẹ gbà awọn ti o gbẹkẹle ọ là,
lọwọ awọn ti o dide si wọn.
8 Pa mi mọ́ bi ọmọ-oju, pa mi mọ́ labẹ
ojiji iyẹ-apá rẹ,
9 Lọwọ awọn enia buburu ti nfõró mi,
lọwọ awọn ọta-iyọta mi, ti o yi mi kakiri.
10 Nwọn fi ọ̀ra sé aiya wọn, ẹnu wọn ni
nwọn fi nsọ̀rọ igberaga.
11 Nwọn ti yi wa ká nisisiyi ninu ìrin
wa; nwọn ti gbé oju wọn le ati wọ́ wa
silẹ:
12 Bi kiniun ti nṣe iwọra si ohun ọdẹ
rẹ̀, ati bi ọmọ kiniun ti o mba ni ibi
ìkọkọ.
13 Dide, Oluwa, ṣaju rẹ̀, rẹ̀ ẹ silẹ: gbà
ọkàn mi lọwọ awọn enia buburu, ti iṣe idà
rẹ:
14 Lọwọ awọn enia ti iṣe ọwọ rẹ, Oluwa,
lọwọ awọn enia aiye, ti nwọn ni ipin wọn
li aiye yi, ati ikùn ẹniti iwọ fi ohun iṣura
rẹ ìkọkọ kún: awọn ọmọ wọn pọ̀, nwọn a
si fi iyokù ini wọn silẹ fun awọn ọmọ-ọwọ
wọn.
15 Bi o ṣe ti emi ni emi o ma wò oju rẹ
li ododo: àworan rẹ yio tẹ mi lọrun ni-
gbati mo ba jí.

## ORIN 18.

*Orin Dafidi, iranṣẹ Oluwa, ẹniti o sọ ọ̀rọ orin yi fun Oluwa li ọjọ ti Oluwa gbà a kuro lọwọ gbogbo awọn ọta rẹ̀, ati lọwọ Saulu.*

EMI o fẹ ọ, Oluwa, agbara mi.
2 Oluwa li apáta mi, ati ilu-olodi mi,
ati olugbala mi: Ọlọrun mi, agbara mi,
emi o gbẹkẹle e; asà mi, ati iwo igbala mi,
ati ile-iṣọ giga mi.
3 Emi o kepè Oluwa, ti o yẹ lati ma yìn;
bẽli a o si gbà mi lọwọ awọn ọta mi.
4 Irora ikú yi mi ka, ati iṣàn-omi awọn
enia buburu dẹ̀ruba mi.
5 Irora ipò okú yi mi kakiri: ikẹkun
ikú dì mi mu.
6 Ninu iṣẹ́ mi emi kepè Oluwa, emi si
sọkun pe Ọlọrun mi: o gbohùn mi lati inu
tempili rẹ̀ wá, ẹkún mi si wá si iwaju rẹ̀,
ani si eti rẹ̀.

Digitized by Google

7 Nigbana ni ilẹ mì, o si wariri: ipilẹ
òke pẹlu ṣidi, o si mì, nitoriti o binu.
8 Ẹfin ti iho imu rẹ̀ jade, ati iná lati ẹnu
rẹ̀ wá njonirun: ẹyín gbiná nipasẹ rẹ̀.
9 O tẹri ọrun ba pẹlu, o si sọkalẹ wá:
òkunkun si mbẹ li abẹ ẹsẹ rẹ̀.
10 O si gùn ori kerubu o si fò: nitõtọ,
o nrà lori iyẹ-apa afẹfẹ.
11 O fi òkunkun ṣe ibi ìkọkọ rẹ̀: aui
agọ rẹ̀ yi i ka kiri; omi dudu, ati awọ-
sanma oju-ọrun ṣiṣu dùdu.
12 Nipa imọlẹ iwaju rẹ̀, awọsanma ṣiṣu
dùdu rẹ̀ kọja lọ, yinyín ati ẹyín iná.
13 Oluwa sán ãra pẹlu li ọrun, Ọga-ogo
si fọ̀ ohùn rẹ̀! yinyín ati ẹyín iná!
14 Lõtọ, o rán ọfa rẹ̀ jade, o si tú wọn
ká: ati ọ̀pọlọpọ manamana li o si fi ṣẹ́ wọn
tũtu.
15 Nigbana li awowò omi odò hàn, a si
ri ipilẹ aiye nipa ibawi rẹ, Oluwa, nipa fi-
fun ẹmi iho imu rẹ.
16 O ranṣẹ lati òke wá, o mu mi, o fà
mi jade wá lati inu omi nla.
17 O gbà mi lọwọ ọta mi alagbara, ati
lọwọ awọn ti o korira mi; nitori nwọn li
agbara jù mi lọ.
18 Nwọn dojukọ mi li ọjọ ipọnju mi:
ṣugbọn Oluwa li alafẹhintì mi.
19 O mu mi jade pẹlu sinu ibi nla; o
gbà mi nitori inu rẹ̀ dùn si mi.
20 Oluwa san a fun mi gẹgẹ bi ododo
mi; gẹgẹ bi mimọ́ ọwọ mi li o san a fun mi.
21 •Nitori mo ti nkiye si ọ̀na Oluwa,
emi kò fi ìka yà kuro lọdọ Ọlọrun mi.
22 Nitori pe gbogbo idajọ rẹ̀ li o wà ni-
waju mi, bẹ̃li emi kò si yẹ̀ ofin rẹ̀ kuro
lọdọ mi.
23 Emi si duro ṣinṣin pẹlu rẹ̀, emi si
paramọ kuro lara ẹ̀ṣẹ mi.
24 Nitorina li Oluwa ṣe san a fun mi
gẹgẹ bi ododo mi, gẹgẹ bi mimọ́ ọwọ mi li
oju rẹ̀.
25 Fun alãnu ni iwọ o fi ara rẹ hàn li
alãnu; fun ẹniti o duro-ṣinṣin ni iwọ o fi
ara rẹ hàn ni diduro-ṣinṣin.
26 Fun ọlọkàn-mimọ́ ni iwọ o fi ara rẹ
hàn ni ọlọkàn-mimọ́; ati fun ọlọkàn-wiwọ
ni iwọ o fi ara rẹ hàn li onroro.
27 Nitori iwọ o gbà awọn olupọnju;
ṣugbọn iwọ o sọ oju igberaga kalẹ.
28 Nitori iwọ ni yio tàn fitila mi: Olu-
wa Ọlọrun mi yio tàn imọlẹ si òkunkun
mi.
29 Nitori pe pẹlu rẹ emi sure là inu
ogun lọ: ati pẹlu Ọlọrun mi emi fò odi
kan.
30 Bi o ṣe ti Ọlọrun ni, ọ̀na rẹ̀ pé: a ti
ridi ọ̀rọ Oluwa: on li apata fun gbogbo
awọn ti o gbẹkẹle e.
31 Nitori pe tani iṣe Ọlọrun, bikoṣe
Oluwa? tabi tani iṣe apáta bikoṣe Ọlọrun
wa?
32 Ọlọrun li o fi agbara dì mi li amure,
o si mu ọ̀na mi pé.
33 O ṣe ẹsẹ mi bi ẹsẹ àgbọnrín, o si gbé
mi kà ibi giga mi.
34 O kọ́ ọwọ mi li ogun jija, tobẹ̃ ti apa
mi fà ọrun idẹ.
35 Iwọ ti fi asà igbala rẹ fun mi pẹlu:
ọwọ ọ̀tun rẹ si gbé mi duro, ati ìwa-pẹlẹ rẹ
sọ mi di nla.
36 Iwọ sọ ìrin ẹsẹ mi di nla nisalẹ mi,
ki kóko-ẹsẹ mi ki o máṣe yẹ̀.
37 Emi ti le awọn ọta mi, emi si bá
wọn: bẹ̃li emi kò pada sẹhin titi a fi run
wọn.
38 Emi ṣá wọn li ọgbẹ ti nwọn kò fi le
dide, nwọn ṣubu li abẹ ẹsẹ mi.
39 Nitoriti iwọ fi agbara dì mi li àmure
si ogun na: iwọ ti mu awọn ti o dide si mi
tẹriba li abẹ ẹsẹ mi.
40 Iwọ si yi ẹhin awọn ọta mi pada fun
mi pẹlu; emi si pa awọn ti o korira mi
run.
41 Nwọn kigbe, ṣugbọn kò si ẹniti o gbà
wọn; ani si Oluwa, ṣugbọn kò dá wọn li
ohùn.
42 Nigbana ni mo gún wọn kunna bi
ekuru niwaju afẹfẹ: mo kó wọn jade bi
egunrin ni ita.
43 Iwọ ti yọ mi kuro ninu ìja awọn
enia; iwọ fi mi jẹ olori awọn orilẹ-ède:
enia ti emi kò ti mọ̀, yio si ma sìn mi.
44 Bi nwọn ti gburo mi, nwọn o gbà mi
gbọ́: awọn ọmọ àjeji yio fi ẹ̀tan tẹ̀ ori wọn
ba fun mi.
45 Aiya yio pá awọn alejo, nwọn o si fi
ibẹ̀ru jade ni ibi kọlọfin wọn.
46 Oluwa mbẹ; olubukún si li apáta
mi; ki a si gbé Ọlọrun igbala mi leke.
47 Ọlọrun li o ngbẹsan mi, ti o si nṣẹ́
awọn enia fun mi.
48 O gbà mi lọwọ awọn ọta mi: pẹlu-
pẹlu iwọ gbé mi leke jù awọn ti o dide si
mi lọ; iwọ ti gbà mi lọwọ ọkọnrin alagba-
ra nì.
49 Nitorina li emi ṣe fi iyìn fun ọ, Olu-
wa, li awujọ awọn orilẹ-ède, emi o si ma
kọrin iyìn si orukọ rẹ.
50 Ẹniti o fi igbala nla fun Ọba rẹ̀; o si
fi ãnu hàn fun Ẹni-ororo rẹ̀, fun Dafidi, ati
fun iru-ọmọ rẹ̀ lailai,

Digitized by Google

## ORIN 19.

AWỌN ọrun nsọ̀rọ ogo Ọlọrun; ati ofu-
rufu nfi iṣẹ ọwọ rẹ̀ hàn.
2 Ọjọ de ọjọ nfọhùn, ati oru de oru nfi
ìmọ hán.
3 Kò si ohùn kan tabi ède kan, nibiti a
kò gbọ́ iró wọn.
4 Iró wọn la gbogbo aiye ja, ati ọ̀rọ wọn
de opin aiye: ninu wọn li o gbe pagọ fun
õrùn.
5 Ti o dabi ọkọ iyawo ti njade ti iyẹwu
rẹ̀ wá, ti o si yọ̀ bi ọkọnrin alagbara lati
sure ije.
6 Ijadelọ rẹ̀ ni lati opin ọrun wá, ati
ayika rẹ̀ si de ipinlẹ rẹ̀; kò si si ohun ti o
fi ara pamọ́ kuro ninu õru rẹ̀.
7 Ofin Oluwa pé, o nyi ọkàn pada: ẹri
Oluwa daniloju, o nsọ ope di ọlọgbọ́n.
8 Ilana Oluwa tọ́, o nmu ọkàn yọ̀: aṣẹ
Oluwa ni mimọ́, o nṣe imọlẹ oju.
9 Ẹ̀ru Oluwa mọ́, pipẹ ni titi lai; idajọ
Oluwa li otitọ, ododo ni gbogbo wọn.
10 Nwọn jù wura daradara pupọ; nwọn
si dùn jù oyin lọ, ati riro afara oyin.
11 Pẹlupẹlu nipa wọn li a ti ṣi iranṣẹ rẹ
leti; ati ni pipamọ́ wọn ere pipọ̀ mbẹ.
12 Tali o le mọ̀ iṣina rẹ̀? wẹ̀ mi mọ́ ku-
ro ninu iṣiṣe ikọkọ mi.
13 Fà iranṣẹ rẹ sẹhin pẹlu kuro ninu ẹ̀ṣẹ
ikugbu: máṣe jẹ ki nwọn ki o jọba lori mi:
nigbana li emi o duro ṣinṣin, emi o si ṣe
alaijẹbi kuro ninu ẹ̀ṣẹ nla nì.
14 Jẹ ki ọ̀rọ ẹnu mi, ati iṣaro ọkàn mi,
ki o ṣe itẹwọgba li oju rẹ, Oluwa, agbara
mi, ati oludande mi.

## ORIN 20.

KI Oluwa ki o gbohùn rẹ li ọjọ ipọnju;
orukọ Ọlọrun Jakobu ki o dàbobo ọ.
2 Ki o rán iranlọwọ si ọ lati ibimimọ́
wá, ki o si tì ọ lẹhin lati Sioni wá.
3 Ki o ranti ẹbọ-ọrẹ rẹ gbogbo, ki o si
gbà ẹbọ sisun rẹ.
4 Ki o fi fun ọ gẹgẹ bi ti inu rẹ, ki o si
mu gbogbo ìmọ rẹ ṣẹ.
5 Awa o ma kọrin ayọ̀ igbala rẹ, ati li
orukọ Ọlọrun wa li awa o fi ọpágun wa de
ilẹ; ki Oluwa ki o mu gbogbo ibère rẹ ṣẹ.
6 Nigbayi ni mo to mọ̀ pe Oluwa gbà
Ẹni-ororo rẹ̀ là; yio gbọ́ ọ lati ọrun mimọ́
rẹ̀ wá nipa agbara igbala ọwọ ọ̀tun rẹ̀.
7 Awọn ẹlomiran gbẹkẹle kẹkẹ́, awọn
ẹlomiran le ẹṣin; ṣugbọn awa o ranti oru-
kọ Oluwa Ọlọrun wa.
8 Nwọn wolẹ, nwọn si ṣubu: ṣugbọn
awa dide awa si duro ṣinṣin.
9 Gbani, Oluwa, ki Ọba ki o gbọ nigbati
awa ba nkigbe pe e.

## ORIN 21.

ỌBA yio ma yọ̀ li agbara rẹ, Oluwa; ati
ni igbala rẹ, yio ti yọ̀ pọ̀ to!
2 Iwọ ti fi ifẹ ọkàn rẹ̀ fun u, iwọ kò si
dù u ni ibère ẹnu rẹ̀.
3 Nitori iwọ ti fi ibukún ore kò o li ọ̀na,
iwọ fi ade kiki wura de e li ori.
4 O tọrọ ẹmi lọwọ rẹ, iwọ si fi fun u,
ani ọjọ gigùn lai ati lailai.
5 Ogo rẹ̀ pọ̀ ni igbala rẹ: iyìn ati ọlánla
ni iwọ fi si i lara.
6 Nitori iwọ ti ṣe e li ẹni-ibukún fun
jùlọ titi aiye: iwọ si fi oju rẹ mu u yọ̀
gidigidi.
7 Nitori ti ọba gbẹkẹle Oluwa, ati nipa
ãnu Ọga-ogo kì yio ṣipò pada.
8 Ọwọ rẹ yio wá gbogbo awọn ọta rẹ ri:
ọwọ ọtún rẹ ni yio wá awọn ti o korira rẹ
ri.
9 Iwọ o ṣe wọn bi ileru onina ni igba
ibinu rẹ: Oluwa yio gbé wọn mì ni ibinu
rẹ̀, iná na yio si jó wọn pa.
10 Eso wọn ni iwọ o run kuro ni ilẹ, ati
irú-ọmọ wọn kuro ninu awọn ọmọ enia.
11 Nitori ti nwọn nrò ibi si ọ: nwọn
ngbìro ete ìwa-ibi, ti nwọn kì yio le ṣe.
12 Nitorina ni iwọ o ṣe mu wọn pẹhinda,
nigbati iwọ ba fi ọfà rẹ kàn ọṣán si oju
wọn.
13 Ki iwọ ki o ma leke, Oluwa, li agba-
ra rẹ; bẽli awa o ma kọrin, ti awa o si ma
yìn agbara rẹ.

## ORIN 22.

ỌLỌRUN mi, Ọlọrun mi, ẽṣe ti iwọ fi kọ̀
mi silẹ? ti iwọ si jina si igbala mi,
ati si ohùn igbe mi?
2 Ọlọrun mi, emi nkigbe li ọsan, ṣugbọn
iwọ kò dahùn: ati ni igba oru emi kò
dakẹ.
3 Ṣugbọn mimọ́ ni Iwọ, ẹniti o tẹ̀ iyìn
Israeli do.
4 Awọn baba wa gbẹkẹle ọ: nwọn gbẹ-
kẹle, iwọ si gbà wọn.
5 Nwọn kigbe pè ọ, a si gbà wọn: nwọn
gbẹkẹle ọ, nwọn kò si dãmu.
6 Ṣugbọn kòkoro li emi, kì isi iṣe enia;
ẹ̀gan awọn enia, ati ẹlẹya awọn enia.
7 Gbogbo awọn ti o ri mi nfi mi rẹrin
ẹlẹya: nwọn nyọ ṣuti ète wọn, nwọn nmì
ori pe,

Digitized by Google

8 Jẹ ki o gbẹkẹle Oluwa, on o gbà a là;
jẹ ki o gbà a là nitori inu rẹ̀ dùn si i.
9 Ṣugbọn iwọ li ẹniti o mu mi jade lati
inu wá: iwọ li o mu mi wà li ailewu, ni-
gbati mo rọ̀ mọ́ ọmu iya mi.
10 Iwọ li a ti fi mi le lọwọ lati inu iya
mi wá: iwọ li Ọlọrun mi lati inu iya mi
wá.
11 Máṣe jina si mi; nitori ti iyọnu sun-
mọ etile; nitoriti kò si oluranlọwọ.
12 Akọ-malu pipọ̀ li o yi mi ka: malu
Baṣani ti o lagbara rọ̀gba yi mi ka.
13 Nwọn yà ẹnu wọn si mi, bi kiniun ti
ndọdẹ kiri, ti nké ramu-ramu.
14 A tú mi danu bi omi, gbogbo egun-
gun mi si yẹ̀ lori ike: ọkàn mi dabi ida;
o yọ́ larin inu mi.
15 Agbara mi di gbigbẹ bi apādi: ahọn
mi si lẹ̀ mọ́ mi li ẹrẹkẹ; iwọ o mu mi
dubulẹ ninu erupẹ ikú.
16 Nitoriti awọn aja yi mi ka: ijọ awọn
enia buburu ti ká mi mọ́: nwọn lu mi li
ọwọ, nwọn si lu mi li ẹsẹ.
17 Mo le kaye gbogbo egungun mi:
nwọn nwò mi ṣùn.
18 Nwọn pín aṣọ mi fun ara wọn, nwọn
si ṣẹ́ keké le aṣọ-ileke mi.
19 Ṣugbọn iwọ máṣe jina si mi, Oluwa:
agbara mi, yara lati ràn mi lọwọ.
20 Gbà ọkàn mi lọwọ idà; ẹni mi kanna
lọwọ agbara aja nì.
21 Gbà mi kuro li ẹnu kiniun nì; ki
iwọ ki o si gbohùn mi lati ibi iwo awọn
agbanrere.
22 Emi o sọ̀rọ orukọ rẹ fun awọn ara-
kọnrin mi: li awujọ ijọ li emi o ma yìn ọ,
23 Ẹnyin ti o bẹ̀ru Oluwa, ẹ yìn i;
gbogbo ẹnyin iru-ọmọ Jakobu, ẹ yìn i logo:
ki ẹ si ma bẹ̀ru rẹ̀ gidigidi, gbogbo ẹnyin
iru ọmọ Israeli.
24 Nitoriti kò kẹgan, bẽni kò korira
ipọnju awọn olupọnju; bẽni kò pa oju rẹ̀
mọ́ kuro lara rẹ̀; ṣugbọn nigbati o kigbe
pè e, o gbọ́.
25 Nipa tirẹ ni iyìn mi yio wà ninu ajọ
nla, emi o san ẹjẹ́ mi niwaju awọn ti o
bẹ̀ru rẹ̀.
26 Awọn olupọnju yio jẹ, yio tẹ́ wọn
lọrun: awọn ti nwá Oluwa yio yìn i: ọkàn
nyin yio wà lailai:
27 Gbogbo opin aiye ni yio ranti, nwọn
o si yipada si Oluwa: ati gbogbo ibatan
orilẹ-ède ni yio wolẹ-sìn niwaju rẹ̀.
28 Nitori ijọba ni ti Oluwa; on si ni
Bãlẹ ninu awọn orilẹ-ède.
29 Gbogbo awọn ti o sanra li aiye yio
ma jẹ, nwọn o si ma wolẹ-sìn: gbogbo awọn
ti nsọkalẹ lọ sinu erupẹ yio tẹriba niwaju
rẹ̀, ati ẹniti kò le pa ọkàn ara rẹ̀ mọ́ li ãye.
30 Iru kan yio ma sìn i; a o si kà a ni
iran kan fun Oluwa.
31 Nwọn o wá, nwọn o si ma sọ̀rọ ododo
rẹ̀ fun awọn enia kan ti a o bí, pe, on li o
ṣe eyi.

## ORIN 23.

OLUWA li Oluṣọ-agutan mi; emi kì yio
ṣe alaini.
2 O mu mi dubulẹ ninu papa-oko tutù;
o mu mi lọ si iha omi didakẹ rọ́rọ́.
3 O tù ọkàn mi lara; o mu mi lọ nipa
ọ̀na ododo nitori orukọ rẹ̀.
4 Nitõtọ, bi mo tilẹ nrìn larin afonifoji
ojiji ikú, emi kì yio bẹ̀ru ibi kan; nitori ti
Iwọ pẹlu mi; ọgọ rẹ ati ọpá rẹ nwọn ntù
mi ninu.
5 Iwọ tẹ́ tabili onjẹ silẹ niwaju mi li oju
awọn ọta mi; iwọ dà ororo si mi li ori;
ago mi si kún akúnwọsilẹ.
6 Nitotọ, ire ati ãnu ni yio ma tọ̀ mi
lẹhin li ọjọ aiye mi gbogbo; emi o si ma
gbe inu ile Oluwa lailai.

## ORIN 24.

TI Oluwa ni ilẹ, ati ẹkún rẹ̀; aiye, ati
awọn ti o tẹdo sinu rẹ̀.
2 Nitoriti o fi idi rẹ̀ sọlẹ lori okun, o si
gbé e kalẹ lori awọn iṣan-omi.
3 Tani yio gùn ori oke Oluwa lọ? tabi
tani yio duro ni ibi-mimọ́ rẹ̀?
4 Ẹniti o li ọwọ mimọ́, ati aiya funfun:
ẹniti kò gbé ọkàn rẹ̀ soke si asan, ti kò si
bura ẹ̀tan.
5 On ni yio ri ibukún gbà lọwọ Oluwa,
ati ododo lọwọ Ọlọrun igbala rẹ̀.
6 Eyi ni iran awọn ti nṣe afẹri rẹ̀, ti nṣe
afẹri rẹ, Ọlọrun Jakobu.
7 Ẹ gbé ori nyin soke, ẹnyin ẹnu-ọ̀na;
ki a si gbé nyin soke, ẹnyin ilẹkun aiye-
raiye: ki Ọba ogo ki o wọ̀ inu ile wa.
8 Tali Ọba ogo yi? Oluwa ti o le, ti o
si lagbara, Oluwa ti o lagbara li ogun.
9 Ẹ gbé ori nyin soke, ẹnyin ẹnu-ọ̀na;
ani ki ẹ gbé wọn soke, ẹnyin ilẹkun aiye-
raiye: ki Ọba ogo ki o wọ̀ inu ile wa.
10 Tali Ọba ogo yi? Oluwa awọn ọmọ-
ogun; on na li Ọba ogo.

## ORIN 25.

OLUWA, iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si.
2 Ọlọrun mi, emi gbẹkẹle ọ: máṣe jẹ

Digitized by Google

ki oju ki o tì mi, máṣe jẹ ki awọn ọta mi
ki o yọ̀ mi.
3 Lõtọ, maṣe jẹ ki oju ki o tì ẹnikẹni ti
o duro tì ọ: awọn ti nṣẹ̀ li ainidi ni oju
yio tì.
4 Fi ọ̀na rẹ hàn mi, Oluwa; kọ́ mi ni
ipa tirẹ.
5 Sin mi li ọ̀na otitọ rẹ, ki o si kọ́ mi:
nitori iwọ li Ọlọrun igbala mi; iwọ ni mo
duro tì li ọjọ gbogbo.
6 Oluwa, ranti ãnu ati iṣeun-ifẹ rẹ ti o
ni irọnu; nitoriti nwọn ti wà ni igba atijọ.
7 Máṣe ranti ẹ̀ṣẹ igba-ewe mi, ati irekọja
mi: gẹgẹ bi ãnu rẹ iwọ ranti mi, Oluwa,
nitori ore rẹ:
8 Rere ati diduro-ṣinṣin ni Oluwa? ni-
torina ni yio ṣe ma kọ́ ẹlẹṣẹ li ọ̀na na.
9 Onirẹlẹ ni yio tọ́ li ọ̀na ni idajọ, ati
onirẹlẹ ni yio kọ́ li ọ̀na rẹ̀.
10 Gbogbo ipa Oluwa li ãnu ati otitọ,
fun irú awọn ti o pa majẹmu rẹ̀ ati ẹri rẹ̀
mọ́.
11 Nitori orukọ rẹ, Oluwa, dari ẹ̀ṣẹ mi
jì, nitori ti o tobi.
12 Ọkọnrin wo li o bẹ̀ru Oluwa? on ni
yio kọ́ li ọ̀na ti yio yàn.
13 Ọkàn rẹ̀ yio joko ninu ire, iru-ọmọ rẹ̀
yio si jogun aiye.
14 Aṣiri Oluwa wà pẹlu awọn ti o bẹ̀ru
rẹ̀, yio si fi wọn mọ̀ majẹmu rẹ̀.
15 Oju mi gbé soke si Oluwa lai; nitori
ti yio fà ẹsẹ mi yọ kuro ninu àwọn na.
16 Yipada si mi, ki o si ṣãnu fun mi;
nitori ti mo di ofo, mo si di olupọnju.
17 Iṣẹ́ aiya mi di pupọ: mu mi jade
ninu ipọnju mi.
18 Wò ipọnju mi ati irora mi; ki o si
dari gbogbo ẹ̀ṣẹ mi jì mi.
19 Wò awọn ọta mi, nwọn sá pọ̀; nwọn
si korira mi ni irira ìka.
20 Pa ọkàn mi mọ́, ki o si gbà mi: máṣe
jẹ ki oju ki o tì mi; nitori mo gbẹkẹ mi
le ọ.
21 Jẹ ki ìwa-titọ ati iduro-ṣinṣin ki o pa
mi mọ́: nitoriti mo duro tì ọ.
22 Rà Israeli pada, Ọlọrun, kuro ninu
ìṣẹ́ rẹ̀ gbogbo.

## ORIN 26.

ṢE idajọ mi, Oluwa; nitori ti mo ti nrìn
ninu ìwa titọ mi; emi ti gbẹkẹle Olu-
wa pẹlu; njẹ ẹsẹ mi kì yio yẹ̀.
2 Wadi mi, Oluwa, ki o si ridi mi; dán
inu mi ati ọkàn mi wò.
3 Nitoriti iṣeun-ifẹ rẹ mbẹ niwaju mi:
emi si ti nrìn ninu otitọ rẹ.
4 Emi kò ba ẹni asan joko, bẹ̃li emi kì
yio ba awọn alayidayida wọle.
5 Emi ti korira ijọ awọn oluṣe-buburu;
emi kì yio si ba awọn enia buburu joko.
6 Emi o wẹ̀ ọwọ mi li ailẹṣẹ: bẹ̃li emi o
si yi pẹpẹ rẹ ká, Oluwa.
7 Ki emi ki o le fi ohùn ọpẹ rò kalẹ, ti
emi o si ma sọrọ gbogbo iṣẹ iyanu rẹ.
8 Oluwa, emi ti nfẹ ibujoko ile rẹ, ibi
agọ ọlá rẹ.
9 Máṣe kó ọkàn mi pọ̀ pẹlu awọn ẹlẹṣẹ,
tabi ẹmi mi pẹlu awọn enia-ẹ̀jẹ.
10 Li ọwọ ẹniti ìwa-ìka mbẹ, ọwọ ọtún
wọn si kún fun abẹtẹlẹ.
11 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi, emi o ma rìn
ninu ìwatitọ mi: rà mi pada, ki o si ṣãnu
fun mi.
12 Ẹsẹ mi duro ni ibi titẹju: ninu awọn
ijọ li emi o ma fi ibukún fun Oluwa.

## ORIN 27.

OLUWA ni imọlẹ mi ati igbala mi; tali
emi o bẹru? Oluwa li agbara ẹmi
mi; aiya tani yio fò mi?
2 Nigbati awọn enia buburu, ani awọn
ọta mi ati awọn abinuku mi sunmọ mi lati
jẹ ẹran ara mi, nwọn kọsẹ, nwọn si ṣubu.
3 Bi ogun tilẹ dótì mi, aiya mi kì yio
fò: bi ogun tilẹ dide si mi, ninu eyi li
ọkàn mi yio le.
4 Ohun kan li emi ntọrọ li ọdọ Oluwa,
on na li emi o ma wakiri: ki emi ki o le
ma gbe inu ile Oluwa li ọjọ aiye mi gbo-
gbo, ki emi ki o le ma wò ẹwà Oluwa, ki
emi ki o si ma fi inudidùn wò tempili rẹ̀.
5 Nitori pe ni igba ipọnju on o pa mi
mọ́ ninu agọ rẹ̀: ni ibi ìkọkọ agọ rẹ̀ ni
yio pa mi mọ́; yio si gbé mi soke kà ori
apata.
6 Nigbayi li ori mi yio gbé soke ga jù
awọn ọta mi lọ, ti o yi mi ka: nitorina
li emi o ṣe rubọ ayọ̀ ninu agọ rẹ̀; emi o
kọrin, nitõtọ emi o kọrin iyìn si Oluwa.
7 Gbọ́, Oluwa, nigbati mo ba fi ohùn
mi pè: ṣanu fun mi pẹlu, ki o si da mi li
ohùn.
8 Nigbati o wipe, Ẹ ma wa oju mi;
ọkàn mi wi fun ọ pe, Oju rẹ, Oluwa, li emi
o ma wá.
9 Máṣe pa oju rẹ mọ́ kuro lọdọ mi;
máṣe fi ibinu ṣa iranṣẹ rẹ tì: iwọ li o ti
nṣe iranlọwọ mi; má fi mi silẹ, bẹ̃ni ki
o máṣe kọ̀ mi, Ọlọrun igbala mi.
10 Nigbati baba ati iya mi kọ̀ mi silẹ,
nigbana ni Oluwa yio tẹwọgbà mi.

Digitized by Google

11 Kọ́ mi li ọ̀na rẹ, Oluwa, ki o si tọ́ mi li ọ̀na titọ nitori awọn ọta mi.

12 Máṣe fi mi le ifẹ awọn ọta mi lọwọ; nitori awọn ẹlẹri eke dide si mi, ati iru awọn ti nmí imi-ìka.

13 Ṣugbọn emi ti gbagbọ lati ri ire Oluwa ni ilẹ alãye.

14 Duro de Oluwa; ki o si tújuka, yio si mu ọ li aiya le: mo ni, duro de Oluwa.

## ORIN 28.

IWỌ, Oluwa, apata mi li emi o kigbe pè, máṣe dakẹ si mi; bi iwọ ba dakẹ si mi, emi o dabi awọn ti o lọ sinu ihò.

2 Gbọ́ ohùn ẹ̀bẹ mi, nigbati mo ba nkigbe pè ọ, nigbati mo ba gbé ọwọ mi soke siha ibi-mimọ́ jùlọ rẹ.

3 Máṣe fà mi lọ pẹlu awọn enia buburu, ati pẹlu awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ, ti nsọ̀rọ alafia si aladugbo wọn, ṣugbọn ìwa-ìka mbẹ̀ li ọkàn wọn.

4 Fi fun wọn gẹgẹ bi iṣe wọn, ati gẹgẹ bi ìwa buburu ete wọn, fi fun wọn nipa iṣẹ ọwọ wọn, fi ère wọn fun wọn.

5 Nitori ti nwọn kò kà iṣẹ Oluwa si, tabi iṣẹ ọwọ rẹ̀; on o run wọn, kì yio si gbé wọn ró.

6 Olubukún ni Oluwa, nitoriti o ti gbọ́ ohùn ẹ̀bẹ mi.

7 Oluwa li agbara ati asà mi; on li aiya mi gbẹkẹle, a si nràn mi lọwọ: nitorina inu mi dùn jọjọ: emi o si ma fi orin mi yìn i.

8 Oluwa li agbara wọn, on si li agbara igbala ẹni-ororo rẹ̀.

9 Gbà awọn enia rẹ là, ki o si busi ilẹini rẹ: ma bọ́ wọn pẹlu, ki o si ma gbé wọn leke lailai.

## ORIN 29.

EFI fun Oluwa, ẹnyin ọmọ awọn alagbara, ẹ fi ogo ati agbara fun Oluwa.

2 Ẹ fi ogo fun Oluwa, ti o yẹ fun orukọ rẹ̀; ẹ ma sìn Oluwa ninu ẹwà ìwa-mimọ́.

3 Ohùn Oluwa mbẹ lori omi pupọ̀: Ọlọrun ogo nsán ãrá: Oluwa mbẹ lori omi pupọ̀.

4 Ohùn Oluwa li agbara; ohùn Oluwa ni ọlánla.

5 Ohùn Oluwa nfà igi kedari ya; lõtọ, Oluwa nfà igi kedari Lebanoni ya.

6 O mu wọn fò pẹlu bi ọmọ-malu; Lebanoni on Sirioni bi ọmọ agbanrere.

7 Ohùn Oluwa nyà ọwọ ina,

8 Ohùn Oluwa nmì aginju; Oluwa nmì aginju Kadeṣi.

9 Ohùn Oluwa li o nmu abo agbọnrin bi, o si fi igbo didi hàn: ati ninu tempili rẹ̀ li olukuluku nsọ̀rọ ogo rẹ̀.

10 Oluwa joko lori iṣan-omi; nitõtọ, Oluwa joko li Ọba lailai.

11 Oluwa yio fi agbara fun awọn enia rẹ̀; Oluwa yio fi alafia busi i fun awọn enia rẹ̀.

## ORIN 30.

*Orin Dafidi fun iya-si-mimọ́.*

EMI o kokiki rẹ, Oluwa; nitori iwọ li o gbé mi leke, ti iwọ kò si jẹ ki awọn ọta mi ki o yọ̀ mi.

2 Oluwa Ọlọrun mi, emi kigbe pè ọ, iwọ si ti mu mi lara da.

3 Oluwa, iwọ ti yọ ọkàn mi jade kuro ninu isa-okú: iwọ o si pa mi mọ́ lãye, ki emi ki o má ba lọ sinu iho.

4 Kọrin si Oluwa, ẹnyin enia rẹ̀ mimọ́, ki ẹ si ma dupẹ ni iranti ìwa-minọ́ rẹ̀.

5 Nitoripe, ni iṣẹju kan ni ibinu rẹ̀ ipẹ́, li ojurere rẹ̀ ni ìye gbe wà; bi ẹkun pẹ di alẹ kan, ṣugbọn ayọ̀ mbọ li owurọ.

6 Ati ninu alafia mi, emi ni, ipò mi kì yio pada lailai.

7 Oluwa, nipa oju-rere rẹ, iwọ ti mu òke mi duro ṣinṣin: nigbati iwọ pa oju rẹ mọ́, ẹnu yọ mi.

8 Emi kigbe pè ọ, Oluwa; ati si Oluwa li emi mbẹ̀bẹ gidigidi.

9 Ere kili o wà li ẹ̀jẹ mi, nigbati mo ba lọ sinu ihò? erupẹ ni yio ma yìn ọ bi? on ni yio ma sọ̀rọ otitọ rẹ bi?

10 Gbọ́, Oluwa, ki o si ṣãnu fun mi: Oluwa, iwọ ma ṣe oluranlọwọ mi.

11 Iwọ ti sọ ikãnu mi di ijó fun mi; iwọ ti bọ aṣọ-ọ̀fọ mi kuro, iwọ si fi ayọ̀ dì mi li àmure.

12 Nitori idi eyi ni ki ogo mi ki o le ma kọrin si ọ, ki o má si ṣe dakẹ. Oluwa Ọlọrun mi, emi o ma fi iyìn fun ọ lailai.

## ORIN 31.

OLUWA, iwọ ni mo gbẹkẹ mi le: máṣe jẹ ki oju ki o tì mi: gbà mi ninu ododo rẹ.

2 Dẹ eti rẹ silẹ si mi: gbà mi nisisiyi: iwọ ma ṣe apata agbara mi, ile-ãbo lati gba mi si.

3 Nitori iwọ li apata mi ati odi mi: nitorina nitori orukọ rẹ ma ṣe itọ́ mi, ki o si ma ṣe amọ̀na mi.

4 Yọ mi jade ninu àwọn ti nwọn nà silẹ fun mi ni ìkọkọ: nitori iwọ li ãbo mi.

5 Li ọwọ rẹ ni mo fi ẹmi mi le: iwọ li
o ti rà mi pada, Oluwa Ọlọrun otitọ.
6 Emi ti korira awọn ẹniti nfiyesi eke
asan: ṣugbọn emi gbẹkẹle Oluwa.
7 Emi o yọ̀, inu mi yio si dùn ninu ãnu
rẹ: nitori ti iwọ ti rò ti iṣẹ́ mi; iwọ ti mọ̀
ọkàn mi ninu ipọnju;
8 Iwọ kò si sé mi mọ́ si ọwọ ọta nì:
iwọ fi ẹsẹ mi tẹlẹ ni ibi àye nla.
9 Ṣãnu fun mi, Oluwa, nitori ti emi wà
ninu iṣẹ́: oju mi fi ibinujẹ run, ọkàn mi
ati inu mi.
10 Emi fi ibinujẹ lò ọjọ mi, ati ọdun mi
ti on ti imi-ẹ̀dun: agbara mi kú nitori ẹ̀ṣẹ
mi, awọn egungun mi si run.
11 Emi di ẹni-ẹ̀gan lãrin awọn ọta mi
gbogbo, pẹlupẹlu lãrin awọn aladugbo mi,
mo si di ẹ̀ru fun awọn ojulumọ mi: awọn
ti o ri mi lode nyẹra fun mi.
12 Emi ti di ẹni-igbagbe kuro ni ìye bi
okú: emi dabi ohun-elo fifọ́.
13 Nitori ti emi ti ngbọ́ ẹ̀gan ọ̀pọ enia:
ẹ̀ru wà niha gbogbo: nigbati nwọn ngbimọ
pọ̀ si mi, nwọn gbiro ati gbà ẹmi mi kuro.
14 Ṣugbọn emi gbẹkẹle ọ, Oluwa: emi
ni, Iwọ li Ọlọrun mi.
15 Igba mi mbẹ li ọwọ rẹ: gbà mi li
ọwọ awọn ọta mi, ati li ọwọ awọn ti nṣe
inunibini si mi,
16 Ṣe oju rẹ ki o mọlẹ si iranṣẹ rẹ lara:
gbà mi nitori ãnu rẹ.
17 Máṣe jẹ ki oju ki o tì mi, Oluwa;
nitori ti emi nkepè ọ; enia buburu ni ki
oju ki o tì, awọn ni ki a mu dakẹ ni isa-
okú.
18 Awọn ète eke ni ki a mu dakẹ; ti
nsọ̀rọ ohun buburu ni igberaga ati li ẹ̀gan
si awọn olododo.
19 Ore rẹ ti tobi to, ti iwọ fi ṣura dè
awọn ti o bẹru rẹ: ore ti iwọ ti ṣe fun awọn
ti o gbẹkẹle ọ niwaju awọn ọmọ enia!
20 Iwọ o pa wọn mọ́ ni ibi ìkọkọ iwaju
rẹ kuro ninu idimọlu awọn enia; iwọ o
pa wọn mọ́ ni ìkọkọ ninu agọ kan kuro
ninu ija ahọn.
21 Olubukún ni Oluwa; nitori ti o ti
fi iṣeun-ifẹ iyanu rẹ̀ hàn mi ni ilu olodi.
22 Nitori ti mo ti wi ni ikanju mi pe,
A ke mi kuro niwaju rẹ: ṣugbọn iwọ gbọ́
ohùn ẹ̀bẹ mi nigbati mo kepè ọ.
23 Ẹ fẹ Oluwa, gbogbo ẹnyin enia rẹ̀
mimọ́: Oluwa npa onigbagbọ̀ mọ́, o si san
a li ọ̀pọlọpọ fun ẹniti nṣe igberaga.
24 Ẹ tujuka, yio si mu nyin li aiya le,
gbogbo ẹnyin ti o ni ireti niti Oluwa.

## ORIN 32.

IBUKÚN ni fun awọn ti a dari irekọja
wọn jì, ti a bò ẹ̀ṣẹ wọn mọlẹ.
2 Ibukún ni fun ọkọnrin na ẹniti Oluwa
kò kà ẹ̀ṣẹ si lọrun, ati ninu ẹmi ẹniti ẹ̀tan
kò si.
3 Nigbati mo dakẹ, egungun mi di gbi-
gbo nitori igbe mi ni gbogbo ọjọ.
4 Nitori li ọsan ati li oru, ọwọ rẹ wuwo
si mi lara: omi ara mi si dabi ọdá-ẹ̀run.
5 Emi jẹwọ ẹ̀ṣẹ mi fun ọ, ati ẹ̀ṣẹ mi li
emi kò si fi pamọ́. Emi wipe, emi o jẹwọ
ìrekọja mi fun Oluwa: iwọ si dari ẹbi ẹ̀ṣẹ
mi jì.
6 Nitori eyi li olukulùku ẹni ìwa-bi-ọlọ-
run yio ma gbadura si ọ ni igba ti a le ri ọ:
nitõtọ ninu iṣan-omi nla, nwọn kì yio sun-
mọ ọdọ rẹ̀.
7 Iwọ ni ibi ipamọ́ mi: iwọ o pa mi mọ́
kuro ninu iṣẹ́; iwọ o fi orin igbala yi mi
ka kiri.
8 Emi o fi ẹsẹ rẹ le ọ̀na, emi o si kọ́ ọ li
ọ̀na ti iwọ o rìn: emi o ma fi oju mi tọ́ ọ.
9 Ki ẹnyin ki o máṣe dabi ẹṣin tabi iba-
ka, ti kò ni iyè ninu: ẹnu ẹniti a kò le ṣe
aifi ijanu bọ̀, ki nwọn ki o má ba sunmọ ọ.
10 Ọ̀pọ ikãnu ni yio wà fun enia bubu-
ru: ṣugbọn ẹniti o ba gbẹkẹlẹ Oluwa, ãnu
ni yio yi i ka kiri.
11 Ki inu nyin ki o dùn niti Oluwa, ẹ si
ma yọ̀, ẹnyin olododo; ẹ si ma kọrin fun
ayọ̀, gbogbo ẹnyin ti aiya nyin duro ṣinṣin.

## ORIN 33.

EMA yọ̀ niti Oluwa, ẹnyin olododo: ni-
toriti iyìn yẹ fun ẹni-diduro-ṣinṣin.
2 Ẹ ma fi duru yìn Oluwa: ẹ ma fi
ohun-elo olokùn mẹwa kọrin si i.
3 Ẹ kọ orin titun si i: ẹ ma fi ọgbọn-
gbọn lù ohun ọnà orin pẹlu ariwo.
4 Nitori ti ọ̀rọ Oluwa tọ́: ati gbogbo iṣẹ
rẹ̀ li a nṣe ninu otitọ.
5 O fẹ otitọ ati idajọ: ilẹ aiye kún fun
ãnu Oluwa.
6 Nipa ọ̀rọ Oluwa li a da awọn ọrun, ati
gbogbo ogun wọn nipa ẽmí ẹnu rẹ̀.
7 O gbá awọn omi okun jọ bi ẹnipe èkiti
kan: o tò ibu jọ ni ile iṣura.
8 Ki gbogbo aiye ki o bẹru Oluwa: ki
gbogbo araiye ki o ma wà ninu ẹ̀ru rẹ̀.
9 Nitori ti o sọ̀rọ, o si ti ṣẹ; o paṣẹ, o si
duro ṣinṣin.
10 Oluwa mu ìmọ awọn orilẹ-ède di
asan: o mu arekereke awọn enia ṣaki.

Digitized by Google

11 Imọ Oluwa duro lailai, ìro inu rẹ̀ lati
irandiran.
12 Ibukún ni fun orilẹ-ède na, Ọlọrun
ẹniti Oluwa iṣe; ati awọn enia na ti o ti
yàn ṣe ini rẹ̀.
13 Oluwa wò lati ọrun wá, o ri gbogbo
ọmọ enia.
14 Lati ibujoko rẹ̀ o wò gbogbo araiye.
15 O ṣe aiya wọn bakanna; o kiyesi
gbogbo iṣẹ wọn.
16 Kò si ọba kan ti a ti ọwọ ọ̀pọ ogun
gba silẹ: kò si alagbara kan ti a fi agbara
pupọ̀ gba silẹ̀.
17 Ohun asan li ẹṣin fun igbala: bẽni
kì yio fi agbara nla rẹ̀ gbàni silẹ.
18 Kiye si i, oju Oluwa mbẹ lara awọn
ti o bẹ̀ru rẹ̀, lara awọn ti nreti ninu ãnu rẹ̀;
19 Lati gba ọkàn wọn la lọwọ ikú, ati
lati pa wọn mọ́ lãye ni igba ìyan.
20 Ọkàn wa duro de Oluwa: on ni iran-
lọwọ wa ati asà wa.
21 Nitori ti ọkàn wa yio yọ̀ niti rẹ̀,
nitori ti awa ti gbẹkẹlẹ orukọ rẹ̀ mimọ́.
22 Ki ãnu rẹ, Oluwa, ki o wà lara wa,
gẹgẹ bi awa ti nṣe ireti rẹ.

## ORIN 34.

*Orin Dafidi, nigbati o yi iwa rẹ̀ pada niwaju Abimeleki; eni tio lé e, ti on si lọ.*

EMI o ma fi ibukún fun Oluwa nigbagbo-
gbo: iyìn rẹ̀ yio ma wà li ẹnu mi titi
lai.
2 Ọkàn mi yio ma ṣogo rẹ̀ niti Oluwa:
awọn onirẹlẹ yio gbọ́, inu wọn yio si ma
dùn.
3 Gbé Oluwa ga pẹlu mi, ki a si jumọ
gbé orukọ rẹ̀ leke.
4 Emi ṣe afẹri Oluwa, o si gbohùn mi;
o si gbà mi kuro ninu gbogbo ìbẹru mi.
5 Nwọn wò o, imọlẹ si mọ́ wọn: oju kò
si tì wọn.
6 Ọkọnrin olupọnju yi kigbe pè, Oluwa
si gbohùn rẹ̀, o si gbà a ninu gbogbo ipọn-
ju rẹ̀:
7 Angeli Oluwa yi awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀ ká,
o si gbà wọn.
8 Tọ́ ọ wò, ki o si ri pe, rere ni Oluwa:
alabukún fun li ọkọnrin na ti o gbẹkẹle e.
9 Ẹ bẹ̀ru Oluwa, ẹnyin enia rẹ̀ mimọ́:
nitoriti kò si aini fun awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀.
10 Awọn ọmọ kiniun a ma ṣe alaini, ebi
a si ma pa wọn: ṣugbọn awọn ti nwá Olu-
wa, kì yio ṣe alaini ohun ti o dara.
11 Wá, ẹnyin ọmọ, fi eti si mi: emi o
kọ́ nyin li ẹ̀ru Oluwa.
12 Ọkọnrin wo li o nfẹ ìye, ti o si nfẹ
ọjọ pipọ, ki o le ma ri rere?
13 Pa ahọn rẹ mọ́ kuro ninu ibi, ati ète
rẹ kuro li ẹ̀tan sisọ.
14 Lọ kuro ninu ibi, ki o si ma ṣe rere;
ma wá alafia, ki o si lepa rẹ̀.
15 Oju Oluwa mbẹ lara awọn olododo,
eti rẹ̀ si ṣi si igbe wọn.
16 Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe bubu-
ru, lati ke iranti wọn kuro lori ilẹ.
17 Awọn olododo nke, Oluwa si gbọ́, o
si yọ wọn jade ninu iṣẹ́ wọn gbogbo.
18 Oluwa mbẹ leti ọdọ awọn ti iṣe oni-
robinujẹ ọkàn; o si gbà iru awọn ti iṣe
onirora ọkàn là.
19 Ọ̀pọlọpọ ni ipọnju olododo; ṣugbọn
Oluwa gbà a ninu wọn gbogbo.
20 O pa gbogbo egungun rẹ̀ mọ́; kò si
ọkan ti o ṣẹ́ ninu wọn.
21 Ibi ni yio pa enia buburu; ati awọn
ti o korira olododo yio jẹbi.
22 Oluwa rà ọkàn awọn iranṣẹ rẹ̀; ọkan
ninu awọn ti o gbẹkẹle e kì yio jẹbi.

## ORIN 35.

OLUWA gbogun tì awọn ti o gbogun tì
mi: fi ìja fun awọn ti mba mi jà.
2 Di asà on apata mu, ki o si dide fun
iranlọwọ mi.
3 Fa ọ̀kọ yọ pẹlu, ki o si dèna awọn ti
nṣe inunibini si mi: wi fun ọkàn mi pe,
emi ni igbala rẹ.
4 Ki nwọn ki o dãmu, ki a si tì awọn ti
nwá ọkàn mi loju: ki a si mu wọn pada,
ki a si dãmu awọn ti ngbiro ipalara mi.
5 Ki nwọn ki o dabi iyangbo niwaju
afẹfẹ: ki angeli Oluwa ki o ma le wọn.
6 Ki ọ̀na wọn ki o ṣokunkun ki o si ma
yọ́; ki angeli Oluwa ki o si ma lepa wọn.
7 Nitori pe, li ainidi ni nwọn dẹ àwọn
wọn silẹ fun mi, nwọn wà iho silẹ fun ọkàn
mi li ainidi.
8 Ki iparun ki o wá si ori rẹ̀ li ojiji;
àwọn rẹ̀ ti o dẹ, ki o mu on tikararẹ̀: ipa-
run na ni ki o ṣubu si.
9 Ọkàn mi yio si ma yọ̀ niti Oluwa: yio
si ma yọ̀ ninu igbala rẹ̀.
10 Gbogbo egungun mi ni yio wipe,
Oluwa, tali o dabi iwọ, ti ngbà talaka
lọwọ awọn ti o lagbara jù u lọ, ani talaka
ati alaini lọwọ ẹniti nfi ṣe ikogun?
11 Awọn ẹlẹri eke dide; nwọn mbi mi
li ohun ti emi kò mọ̀.
12 Nwọn fi buburu san ore fun mi, lati
sọ ọkàn mi di ofo.
13 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, nigbati ara

Digitized by Google

wọn kò dá, aṣọ àwẹ li aṣọ mi: mo fi àwẹ
rẹ̀ ọkàn mi silẹ; adura mi si pada si mi li
aiya.
14 Emi ṣe ara mi bi ẹnipe ọrẹ tabi ara-
kọnrin mi tilẹ ni: emi fi ibinujẹ tẹriba, bi
ẹniti nṣọ̀fọ iya rẹ̀.
15 Ṣugbọn ninu ipọnju mi nwọn yọ̀,
nwọn si kó ara wọn jọ: awọn enia-kenia
kó ara wọn jọ si mi, emi kò si mọ̀; nwọn
fa mi ya, nwọn kò si dakẹ.
16 Pẹlu awọn àgabagebe ti iṣe ẹlẹya li
apejẹ, nwọn npa ehin wọn si mi.
17 Oluwa iwọ o ti ma wò pẹ to? yọ
ọkàn mi kuro ninu iparun wọn, ẹni mi
kanna lọwọ awọn kiniun.
18 Emi o ṣọpẹ fun ọ ninu ajọ nla: emi
o ma yìn ọ li awujọ ọ̀pọ enia.
19 Máṣe jẹ ki awọn ti nṣe ọta mi lodi ki
o yọ̀ mi; bẹ̃ni ki o má si ṣe jẹ ki awọn ti o
korira mi li ainidi ki o ma ṣẹju si mi.
20 Nitori ti nwọn kò sọ̀rọ alafia: ṣugbọn
nwọn humọ ọ̀ran ẹ̀tan si awọn enia jẹjẹ
ilẹ na.
21 Nitotọ, nwọn ya ẹnu wọn silẹ si mi,
nwọn wipe, A! ã! oju wa ti ri i!
22 Eyi ni iwọ ti ri, Oluwa: máṣe dakẹ:
Oluwa máṣe jina si mi.
23 Rú ara rẹ soke, ki o si ji si idajọ mi,
ati si ọ̀ran mi, Ọlọrun mi ati Oluwa mi.
24 Ṣe idajọ mi, Oluwa Ọlọrun mi, gẹgẹ
bi ododo rẹ, ki o má si ṣe jẹ ki nwọn ki o
yọ̀ mi.
25 Máṣe jẹ ki nwọn kí o wi ninu ọkàn
wọn pe, A! bẹ̃li awa nfẹ ẹ: máṣe jẹ ki
nwọn ki o wipe, Awa ti gbé e mì.
26 Ki oju ki o tì wọn, ki nwọn ki o si
dãmu pọ̀, ti nyọ̀ si ifarapa mi: ki a fi itiju
ati àbukun wọ̀ wọn li aṣọ, ti ngberaga si
mi.
27 Jẹ ki nwọn ki o ma hó fun ayọ̀, ki
nwọn ki o si ma ṣe inu-didùn, ti nṣe oju-
rere si ododo mi: lõtọ ki nwọn ki o ma wi
titi pe, Oluwa ni ki a ma gbega, ti o ni
inu-didùn si alafia iranṣẹ rẹ̀.
28 Ahọn mi yio si ma sọ̀rọ ododo rẹ, ati
ti iyìn rẹ ni gbogbo ọjọ.

## ORIN 36.

IREKỌJA enia buburu wi ninu ọkàn mi
pe; ẹ̀ru Ọlọrun kò si niwaju rẹ̀.
2 Nitoriti o npọ́n ara rẹ̀ li oju ara rẹ̀,
titi a o fi ri ẹ̀ṣẹ rẹ̀ lati korira;
3 Ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ li ẹ̀ṣẹ on ẹ̀tan: o ti fi ọgbọ́n
ati iṣe rere silẹ,
4 O ngbìro ìwa-ika lori ẹni rẹ̀: o gba
ọ̀na ti kò dara; on kò korira ibi.
5 Oluwa, ãnu rẹ de ọrun; otitọ rẹ de
awọsanma.
6 Ododo rẹ dabi awọn òke Ọlọrun; idajọ
rẹ dabi ibu nla: Oluwa, iwọ pa enia ati
ẹranko mọ́.
7 Ọlọrun, iṣeun-ifẹ rẹ ti dara to! nitori
na li awọn ọmọ enia yio ma gbẹkẹ wọn le
abẹ ojiji iyẹ-apa rẹ.
8 Ororo ile rẹ yio tẹ wọn lọrùn gidigidi;
iwọ o si mu wọn mumi ninu odò ifẹ rẹ.
9 Nitori pe pẹlu rẹ li orisun ìye wà:
ninu imọlẹ rẹ li awa o ma ri imọlẹ.
10 Mu iṣeun ifẹ rẹ pẹ si awọn ti o mọ̀ ọ;
ati ododo rẹ fun awọn alaiyà diduro.
11 Máṣe jẹ ki ẹsẹ agberaga ki o wá si
mi, ki o má si jẹ ki ọwọ enia buburu ki o
ṣi mi ni ipò.
12 Nibẹ li awọn oniṣẹ-ẹ̀ṣẹ gbe ṣubu: a
rẹ̀ wọn silẹ, nwọn kì yio si le dide.

## ORIN 37.

MÁṢE ikanra nitori awọn oluṣe-buburu,
ki iwọ ki o máṣe ilara nitori awọn
oniṣẹ ẹ̀ṣẹ.
2 Nitori ti a o ke wọn lulẹ laipẹ bi
koriko, nwọn o si rọ bi eweko tutù.
3 Gbẹkẹle Oluwa, ki o si ma ṣe rere; ma
gbe ilẹ na, ki o si ma huwa otitọ.
4 Ṣe inu-didùn si Oluwa pẹlu, on o si fi
fẹ inu rẹ̀ fun ọ.
5 Fi ọ̀na rẹ̀ le Oluwa lọwọ; gbẹkẹle e
pẹlu; on o si mu u ṣẹ.
6 Yio si mu ododo rẹ jade bi imọlẹ, ati
idajọ rẹ bi ọsángangan.
7 Iwọ simi ninu Oluwa, ki o si fi sũru
duro dè e; máṣe ikanra nitori ẹniti o nri
rere li ọ̀na rẹ̀, nitori ọkọnrin na ti o nmu
èro buburu ṣẹ.
8 Dakẹ inu-bibi, ki o si kọ̀ ikannu silẹ:
máṣe ikanra, ki o má ba ṣe buburu pẹlu.
9 Nitori ti a o ke awọn oluṣe buburu
kuro: ṣugbọn awọn ti o duro de Oluwa ni
yio jogun aiye.
10 Nitori pe nigba diẹ, awọn enia bubu-
ru kì yio si: nitotọ iwọ o fi ara balẹ wò
ipò rẹ̀, kì yio si si.
11 Ṣugbọn awọn ọlọkàn-tutù ni yio jo-
gun aiye; nwọn o si ma ṣe inu didùn ninu
ọ̀pọlọpọ alafia.
12 Enia buburu di rikiṣi si olõtọ, o si pa
ehin rẹ̀ keke si i lara.
13 Oluwa yio rẹrin rẹ̀; nitori ti o ri pe,
ọjọ rẹ̀ mbọ̀.
14 Awọn enia buburu ti fà idà yọ, nwọn
si ti fà ọrun wọn le, lati sọ talaka ati alaini
kalẹ, ati lati pa iru awọn ti nrin li ọ̀na titọ.

Digitized by Google

5 Idà wọn yio wọ̀ aiya wọn lọ, ọrun
yio si ṣẹ́.
6 Ohun diẹ ti olododo ni sanju ọrọ̀ ọ̀pọ
buburu.
7 Nitoriti a o ṣẹ́ apa awọn enia buburu:
bọn Oluwa di olododo mu.
8 Oluwa mọ̀ ọjọ ẹni iduro-ṣinṣin: ati
ni wọn yio wà lailai.
9 Oju kì yio tì wọn ni igba ibi: ati li
ìyan a o tẹ́ wọn lọrun.
0 Ṣugbọn awọn enia buburu yio ṣegbe,
n ọta Oluwa yio dabi ẹwà oko-tutu:
n o run; ẽfin ni nwọn o run si.
1 Awọn enia buburu wín, nwọn kò si
a san: ṣugbọn olododo a ma ṣãnu, a si
fi funni.
2 Nitoriti awọn ẹni-ibukún rẹ̀ ni yio
n aiye; awọn ẹni-egún rẹ̀ li a o ke
o.
3 A ṣe ìlana ẹsẹ enia lati ọwọ Oluwa
: o si ṣe inu didùn si ọ̀na rẹ̀.
4 Bi o tilẹ ṣubu, a kì yio ta a nù kuro
apata; nitoriti Oluwa di ọwọ rẹ̀ mu.
5 Emi ti wà li ewe, emi si dagba; emi
ti iri ki a kọ̀ olododo silẹ, tabi ki iru-
ọ rẹ̀ ki o ma ṣagbe onjẹ.
6 Alãnu li on nigbagbogbo, a ma wín
a si ma busi ifun iru-ọmọ rẹ̀.
7 Kuro ninu ibi ki o si ma ṣe rere; ki
i ma joko lailai.
8 Nitoriti Oluwa fẹ idajọ, kò si kọ̀ awọn
a mimọ́ rẹ̀ silẹ; a si pa wọn mọ́ lailai:
bọn iru-ọmọ awọn enia buburu li a o ke
o.
9 Olododo ni yio jogun aiye, yio si ma
inu rẹ̀ lailai.
0 Ẹnu olododo ni ima sọ̀rọ ọgbọ́n, ahọn
si ma sọ̀rọ idajọ.
1 Ofin Ọlọrun rẹ̀ mbẹ li aiya rẹ̀; ọkan
u ìrin rẹ̀ kì yio yẹ̀.
2 Ẹni buburu nṣọ olododo, o si nwá
lati pa a.
3 Oluwa kì yio fi i le e lọwọ, kì yio si
lẹbi, nigbati a ba nṣe idajọ rẹ̀.
4 Duro de Oluwa, ki o si ma pa ọ̀na rẹ̀
yio si gbé ọ leke lati jogun aiye: ni-
ti a ba ké awọn enia buburu kuro, iwọ o

5 Emi ti nri enia buburu, ẹni ìwa-ika, o
ara rẹ̀ gbilẹ bi igi tutu nla.
6 Ṣugbọn o kọja lọ, si kiyesi i, kò sí
: lõtọ emi wá a kiri, ṣugbọn a kò le

7 Ma kiyesi ẹni pipé, ki o si ma wò ẹni
uro ṣinṣin: nitori alafia li opin ọkọnrin

38 Ṣugbọn awọn alarekọja li a o parun
pọ̀; iran awọn enia buburu li a o ké kuro.
39 Ṣugbọn lati ọwọ Oluwa wá ni igbala
awọn olododo; on li àbo wọn ni igba
ipọnju.
40 Oluwa yio si ràn wọn lọwọ, yio si
gbà wọn, yio si gbà wọn lọwọ enia buburu,
yio si gbà wọn la, nitoriti ti nwọn gbẹkẹle e.

## ORIN 38.

OLUWA, máṣe ba mi wi ninu ibinu rẹ:
bẽni ki o máṣe nà mi ni gbigbona
ibinujẹ rẹ.
2 Nitori ti ọfà rẹ kàn mọ́ mi ṣinṣin, ọwọ
rẹ si kì mi wọ̀ mọlẹ.
3 Kò si ibi yiyè li ara mi nitori ibinu rẹ;
bẽni kò si alafia li egungun mi nitori ẹ̀ṣẹ
mi.
4 Nitori ti ẹbi ẹ̀ṣẹ mi bori mi mọlẹ, bi
ẹrù wuwo, o wuwo jù fun mi.
5 Ọgbẹ mi nrùn, o si dibajẹ nitori were
mi.
6 Emi njowere; ori mi tẹ̀ ba gidigidi;
emi nṣọ̀fọ rinkiri li gbogbo ọjọ.
7 Nitoriti iha mi kún fun àrun ẹgbin;
kò si si ibi yiyè li ara mi.
8 Ara mi hù, o si kan bajẹ: emi ti nke-
rora nitori aisimi aiya mi.
9 Oluwa, gbogbo ifẹ mi mbẹ niwaju rẹ;
ikẹrora mi kò si pamọ́ kuro lọdọ rẹ.
10 Aiya mi nmi-hẹlẹ, agbara mi yẹ̀ mi
silẹ: bi o ṣe ti imọlẹ oju mi ni, kò si lara
mi.
11 Awọn olufẹ ati awọn ọrẹ mi duro li
òkere kuro ni ìna mi, ati awọn ibatan mi
duro li òkere rére.
12 Awọn pẹlu ti nwá ọkàn mi dẹkùn
silẹ fun mi; ati awọn ti nwá ifarapa mi
nsọ̀rọ ohun buburu, nwọn si ngbiro ẹ̀tan ni
gbogbo ọjọ.
13 Ṣugbọn emi, bi aditi, emi kò gbọ́;
ati bi odi ti kò ya ẹnu rẹ̀.
14 Bẽni mo dabi ọkọnrin ti kò gbọ́ran,
ati li ẹnu ẹniti iyàn kò si.
15 Nitori, Oluwa, iwọ li emi duro dè,
iwọ o gbọ́, Oluwa Ọlọrun mi.
16 Nitori ti mo wipe, Gbohùn mi, ki
nwọn ki o má ba yọ̀ mi; nigbati ẹsẹ mi ba
yọ́, nwọn o ma gbé ara wọn ga si mi.
17 Emi ti mura ati ṣubu, ikãnu mi sí
mbẹ nigbagbogbo niwaju mi.
18 Nitori ti emi o jẹwọ ẹ̀ṣẹ mi; emi o
kãnu nitori ẹ̀ṣẹ mi.
19 Ṣugbọn ara yá awọn ọta mi, ara wọn
le; awọn ti o korira mi lodi npọ̀ si i.

Digitized by Google

20 Awọn ti o si nfi buburu san rere li ọta mi; nitori emi ntọpa ohun ti iṣe rere.

21 Oluwa, máṣe kọ̀ mi silẹ; Ọlọrun mi, máṣe jina si mi.

22 Yara lati ran mi lọwọ, Oluwa igbala mi.

## ORIN 39.

MO ni, emi o ma kiyesi ọ̀na mi, ki emi ki o má fi ahọn mi ṣẹ̀; emi o fi ijanu ko ara mi li ẹnu nigbati enia buburu ba mbẹ niwaju mi.

2 Mo fi idakẹ yadi, mo tilẹ pa ẹnu mi mọ́ kuro li ọ̀rọ rere: ibinujẹ mi si ru soke.

3 Aiya mi gbona ninu mi, nigbati emi nronu, ina ràn: nigbana ni mo fi ahọn mi sọ̀rọ.

4 Oluwa, jẹ ki emi ki o mọ̀ opin mi ati ìwọn ọjọ mi, bi o ti ri; ki emi ki o le mọ̀ ìgbà ti mo ni nihin.

5 Kiyesi i, iwọ ti sọ ọjọ mi dabi ibu atẹlẹwọ; ọjọ ori mi si dabi asan niwaju rẹ: nitõtọ olukuluku enia ninu ijoko rere rẹ̀ asan ni patapata.

6 Nitotọ li àworan asan li enia gbogbo nrìn: nitotọ ni nwọn nyọ ara wọn lẹnu li asan: o nkó ọrọ̀ jọ, kò si mọ̀ ẹniti yio kó wọn lọ.

7 Njẹ nisisiyi, Oluwa kini mo duro de? ireti mi mbẹ li ọdọ rẹ.

8 Gbà mi ninu irekọja mi gbogbo: ki o má si sọ mi di ẹni ẹ̀gan awọn enia buburu.

9 Mo yadi, emi kò ya ẹnu mi; nitoripe iwọ li o ṣe e.

10 Mu ọwọ ìna rẹ kuro li ara mi: emi ṣegbe tan nipa ìja ọwọ rẹ.

11 Nigbati iwọ ba fi ibawi kilọ fun enia nitori ẹ̀ṣẹ, iwọ a ṣe ẹwà rẹ̀ aparun bi kòkoro aṣọ: nitõtọ asan li enia gbogbo.

12 Oluwa, gbọ́ adura mi, ki o si fi eti si ẹkún mi, ki o màṣe pa ẹnu rẹ mọ́ si omije mi: nitori alejo li emi lọdọ rẹ, ati atipo, bi gbogbo awọn baba mi ti ri.

13 Da mi si, ki emi li agbara, ki emi ki o to lọ kuro nihinyi, ati ki emi ki o to ṣe alaisi.

## ORIN 40.

NI diduro emi duro de Oluwa: o si dẹti si mi, o si gbohun ẹkún mi.

2 O si mu mi gòke pẹlu lati inu iho iparun jade wá, lati inu erupẹ ẹrẹ̀, o si fi ẹsẹ mi ka ori apata, o si fi iṣisẹ mi lelẹ.

3 O si fi orin titun si mi li enu, ani orin iyìn si Ọlọrun wa: ọ̀pọ enia ni yio ri i, ti yio si bẹ̀ru, ti yio si gbẹkẹle Oluwa.

4 Ibukún ni fun ọkọnrin na ti o fi Oluwa ṣe igbẹkẹle rẹ̀, ti kò si ka onirera si, tabi iru awọn ti nyà si iha eke.

5 Oluwa Ọlọrun mi ọ̀pọlọpọ ni iṣẹ iyanu ti iwọ ti nṣe, ati ìro inu rẹ sipa ti wa: a kò le kà wọn fun ọ li ẹsẹ-ẹsẹ: bi emi o wi ti emi o sọ̀rọ wọn, nwọn jù ohun kikà lọ.

6 Ẹbọ ati ọrẹ iwọ kò fẹ: eti mi ni iwọ ti ṣi: ọrẹ-ẹbọ sisun, ati ọrẹ-ẹbọ ẹ̀ṣẹ on ni iwọ kò bère.

7 Nigbana ni mo wipe, Kiyesi i, emi de: ninu àpo-iwe nì li a gbe kọwe mi pe,

8 Inu mi dùn lati ṣe ifẹ rẹ, Ọlọrun mi, nitõtọ, ofin rẹ mbẹ li aiya mi.

9 Emi ti wãsu ododo ninu awujọ nla: kiyesi i, emi kò pa ete mi mọ́, Oluwa, iwọ mọ̀.

10 Emi kò fi ododo rẹ sin li aiya mi, emi o sọ̀rọ otitọ ati igbala rẹ: emi kò si pa iṣeun-ifẹ rẹ ati otitọ rẹ mọ́ kuro lọdọ ijọ nla nì.

11 Iwọ máṣe fa ãnu rẹ ti o rọnu sẹhin kuro lọdọ mi, Oluwa: ki iṣeun-ifẹ rẹ ati otitọ rẹ ki o ma pa mi mọ́ nigbagbogbo.

12 Nitoripe ainiye ibi li o yi mi ka kiri: ẹ̀ṣẹ mi dì mọ mi, bẹ̃li emi kò le gbé oju wò oke, nwọn jù irun ori mi lọ: nitorina aiya mi npá mi.

13 Ki o wù ọ, Oluwa, lati gbà mi: Oluwa, yara lati ràn mi lọwọ,

14 Ki oju ki o tì wọn, ki nwọn ki o si dãmu pọ̀ awọn ti nwá ọkàn mi lati pa a run; ki a lé wọn pada sẹhin, ki a si dojuti awọn ti nfẹ mi ni ibi.

15 Ki nwọn ki o di ofo fun ère itiju wọn, awọn ti nwi fun mi pe, A! a!

16 Ki gbogbo awọn ti nwá ọ, ki o ma yọ̀, ki inu wọn ki o si ma dùn sipa tirẹ: ki gbogbo awọn ti o si fẹ igbala rẹ ki o ma wi nigbagbogbo pe, Gbigbega li Oluwa.

17 Ṣugbọn talaka ati alaini li emi; Oluwa si nṣe iranti mi; iwọ ni iran-lọwọ mi ati olugbala mi: máṣe pẹ titi, Ọlọrun mi.

## ORIN 41.

IBUKÚN ni fun ẹniti nrò ti awọn alaini, Oluwa yio gbà a ni ìgbà ipọnju.

2 Oluwa yio pa a mọ́, yio si mu u wà lãye: a o si bukún fun u lori ilẹ: iwọ kì yio si fi i le ifẹ awọn ọta rẹ̀ lọwọ.

3 Oluwa yio gbà a ni iyanju lori ẹní

Digitized by Google

àrun: iwọ o tẹ ẹní rẹ̀ gbogbo ni ibulẹ arun
rẹ̀.
4 Emi wipe, Oluwa ṣãnu fun mi: mu
ọkàn mi lara da; nitori ti mo ti ṣẹ̀ si ọ.
5 Awọn ọta mi nsọ ibi si mi pe, nigbawo
ni on o kú, ti orukọ rẹ̀ yio si run?
6 Bi o ba si wá wò mi, on a ma sọ̀rọ
ẹ̀tan: aiya rẹ̀ kó ẹ̀ṣẹ jọ si ara rẹ̀; nigbati
o ba jade lọ, a ma wi i.
7 Gbogbo awọn ti o korira mi jumọ
nsọ̀rọ kẹlẹ si mi: emi ni nwọn ngbìmọ
ibi si.
8 Pe, ohun buburu li o dì mọ ọ ṣinṣin:
ati ibiti o dubulẹ si, kì yio dide mọ.
9 Nitõtọ ọrẹ-iyọrẹ ara mi, ẹniti mo gbẹ-
kẹle, ẹniti njẹ ninu onjẹ mi, o gbe gigisẹ
rẹ̀ si mi.
10 Ṣugbọn iwọ, Oluwa, ṣãnu fun mi, ki
o si gbé mi dide, ki emi ki o le san a fun
wọn.
11 Nipa eyi ni mo mọ̀ pe iwọ ṣe oju-rere
si mi, nitoriti awọn ọta mi kò yọ̀ mi.
12 Bi o ṣe ti emi ni, iwọ dì mi mu ninu
ìwatitọ mi, iwọ si gbé mi kalẹ niwaju rẹ
titi lai.
13 Olubukún ni Oluwa, Ọlọrun Israeli,
lailai titi lai. Amin, Amin.

---

## IWE II.

### ORIN 42.

BI agbọnrin iti ma mi hẹlẹ si ipadò omi,
Ọlọrun, bẽli ọkàn mi nmi hẹlẹ si ọ.
2 Ongbẹ Ọlọrun ngbẹ ọkàn mi, ti Ọlọrun
alãye: nigbawo li emi o wá, ti emi o si
yọju niwaju Ọlọrun.
3 Omije mi li onjẹ mi li ọsan ati li oru,
nigbati nwọn nwi fun mi nigbagbogbo pe,
Ọlọrun rẹ dà?
4 Nigbati mo ba ranti nkan wọnyi, emi
tú ọkàn mi jade ninu mi: emi ti ba ọ̀pọ
ijọ enia lọ, emi ba wọn lọ si ile Ọlọrun,
pẹlu ohùn ayọ̀ on iyìn, pẹlu ọ̀pọ enia ti
npa ọjọ mimọ́ mọ́.
5 Ẽṣe ti ori rẹ fi tẹ̀ba, iwọ ọkàn mi? ẽṣe
ti ara rẹ kò fi lelẹ ninu mi? iwọ ṣe ireti
niti Ọlọrun: nitori emi o sa ma yìn i sibẹ
fun iranlọwọ oju rẹ̀.
6 Ọlọrun mi, ori ọkàn mi tẹ̀ ba ninu
mi: nitorina li emi o ṣe ranti rẹ lati ilẹ
Jordani wá, ati lati Hermoni, lati òke
Misari wá.
7 Ibu omi npè ibu omi nipa hihó ṣiṣan-
omi rẹ: gbogbo riru omi ati bibì omi rẹ bò
mi mọlẹ.
8 Ṣugbọn Oluwa yio paṣẹ iṣeun-ifẹ rẹ̀
nigba ọ̀san, ati li oru orin rẹ̀ yio wà pẹlu
mi, ati adura mi si Ọlọrun ẹmi mi.
9 Emi o wi fun Ọlọrun, apata mi pe,
Ẽṣe ti iwọ fi gbagbe mi? ẽṣe ti emi fi nrìn
ni ìgbawẹ nitori inilara ọta nì.
10 Bi ẹnipe idà ninu egungun mi li
ẹ̀gan ti awọn ọta mi ngàn mi; nigbati
nwọn nwi fun mi lojojumọ pe, Ọlọrun rẹ
dà?
11 Ẽṣe ti ori rẹ fi tẹ̀ba, iwọ ọkàn mi?
ẽṣe ti ara rẹ kò fi lelẹ ninu mi? iwọ ṣe ireti
niti Ọlọrun; nitori emi o sa ma yìn i sibẹ
ẹniti iṣe iranlọwọ oju mi ati Ọlọrun mi.

### ORIN 43.

ṢE idajọ mi, Ọlọrun, ki o si gbà ọ̀ran mi
rò si alailãnu orilẹ-ède: gbà mi lọwọ
ẹlẹtan ati ọkọnrin alaiṣõtọ nì.
2 Nitori iwọ li Ọlọrun agbara mi: ẽṣe ti
iwọ fi ṣa mi tì? ẽṣe ti emi fi nrìn ni igbawẹ
nitori inilara ọta nì.
3 Rán imọlẹ rẹ ati otitọ rẹ jade, ki nwọn
ki o ma ṣe amọna mi: ki nwọn ki o mu mi
gùn òke mimọ́ rẹ, ati sinu agọ rẹ wọnni.
4 Nigbana li emi o lọ si ibi pẹpẹ Ọlọrun,
sọdọ Ọlọrun ayọ̀ nla mi: nitõtọ, lara duru
li emi o ma yìn ọ, Ọlọrun, Ọlọrun mi.
5 Ẽṣe ti ori rẹ fi tẹ̀ba, iwọ ọkàn mi? ẽṣe
ti ara rẹ kò fi lelẹ ninu mi? iwọ ṣe ireti
niti Ọlọrun: nitoriti emi o sa ma yìn i
sibẹ, ẹniti iṣe iranlọwọ oju mi, ati Ọlọrun
mi.

### ORIN 44.

ỌLỌRUN, awa ti fi eti wa gbọ́, awọn baba
wa si ti sọ fun wa ni iṣẹ nla ti iwọ ṣe
li ọjọ wọn, ni ìgbà ọjọ-jọjọ.
2 Bi iwọ ti fi ọwọ rẹ lé awọn keferi jade,
ti iwọ si gbin wọn: bi iwọ ti fõró awọn
enia na, ti iwọ si mu wọn gbilẹ.
3 Nitoriti nwọn kò ni ilẹ na nipa idà ara
wọn, bẽni kì iṣe apá wọn li o gbà wọn; bi-
koṣe ọwọ ọtún rẹ ati apá rẹ, ati imọlẹ oju
rẹ, nitoriti iwọ ni ifẹ rere si wọn.
4 Iwọ li Ọba mi, Ọlọrun: paṣẹ igbala
fun Jakobu.
5 Nipasẹ rẹ li awa o bì awọn ọta wa
ṣubu: nipasẹ orukọ rẹ li awa o tẹ̀ awọn ti
o dide si wa mọlẹ.
6 Nitoriti emi kì yio gbẹkẹle ọrun mi,
bẽni idà mi kì yio gbà mi.
7 Ṣugbọn iwọ li o ti gbà wa lọwọ awọn
ọta wa, iwọ si ti dojutì awọn ti o korira wa.
8 Niti Ọlọrun li awa nkọrin iyìn li ọjọ
gbogbo, awa si nyìn orukọ rẹ lailai.

Digitized by Google

9 Ṣugbọn iwọ ti ṣa ti, iwọ si ti dojuti
wa: iwọ kò si ba ogun wa jade lọ.
10 Iwọ mu wa pẹhinda fun ọta wa: ati
awọn ti o korira wa nṣe ikogun fun ara
wọn.
11 Iwọ ti fi wa fun jijẹ bi ẹran agutan;
iwọ si ti tú wa ka ninu awọn keferi.
12 Iwọ ti tà awọn enia rẹ li asan, iwọ kò
si fi iye-owo wọn sọ ọrọ̀ rẹ di pupọ.
13 Iwọ sọ wa di ẹ̀gan si awọn aladugbo
wa, ẹlẹya ati iyọṣuti-si, si awọn ti o yi ni ka.
14 Iwọ sọ wa di ẹni-owe ninu awọn
orilẹ-ède, ati imirisi ninu awọn enia.
15 Idamu mi mbẹ niwaju mi nigba-
gbogbo, itiju mi si bò mi mọlẹ.
16 Nitori ohùn ẹniti ngàn, ti o si nsọ̀rọ
buburu; nitori ipa ti ọta olugbẹsan ni.
17 Gbogbo wọnyi li o de si wa; ṣugbọn
awa kò gbagbe rẹ, bẹ̃li awa kò ṣe eke ni
majẹmu rẹ.
18 Aiya wa kò pada sẹhin, bẹ̃ni ìrin wa
kò yà kuro ni ipa tirẹ;
19 Bi iwọ tilẹ ti fọ́ wa bajẹ ni ibi awọn
ọ̀wawa, ti iwọ si fi ojiji ikú bò wa mọlẹ.
20 Bi o ba ṣepe awa gbagbe orukọ Ọlọ-
run wa, tabi bi awa ba nà ọwọ wa si ọlọrun
ajeji;
21 Njẹ Ọlọrun ki yio ri idi rẹ̀? nitori o
mọ̀ ohun ìkọkọ aiya.
22 Nitõtọ, nitori rẹ li a ṣe npa wa kú ni
gbogbo ọjọ; a nkà wa si bi agutan fun pipa.
23 Ji! ẽṣe ti iwọ nsùn, Oluwa? dide,
máṣe ṣa wa ti kuro lailai.
24 Ẽṣe ti iwọ fi pa oju rẹ mọ́, ti iwọ si
fi gbagbe ipọnju wa ati inira wa?
25 Nitoriti a tẹri ọkàn wa ba sinu
ekuru: inu wa dì mọ erupẹ ilẹ.
26 Dide fun iranlọwọ wa, ki o si rà wa
pada nitori ãnu rẹ.

## ORIN 45.

AIYA mi nhumọ̀ ọ̀ran rere: emi nsọ
ohun ti mo ti ṣe fun ọba ni: kalamu
ayawọ akọwe li ahọn mi.
2 Iwọ yanju jù awọn ọmọ enia lọ: a dà
ore-ọfẹ si ọ li ète: nitorina li Ọlọrun nbu-
kún fun ọ lailai.
3 San idà rẹ mọ idi rẹ, Alagbara julọ,
ani ogo rẹ ati ọlá-nla rẹ.
4 Ati ninu ọlá-nla rẹ ma gẹṣin lọ li
alafia, nitori otitọ ati ìwa-tutu ati ododo;
ọwọ ọtún rẹ yio si kọ́ ọ li ohun ẹ̀ru.
5 Ọfa rẹ mu li aiya awọn ọta ọba; awọn
enia nṣubu nisalẹ ẹsẹ rẹ.
6 Ọlọrun, lai ati lailai ni itẹ́ rẹ: ọpá-
alade ijọba rẹ ọpá-alade otitọ ni.
7 Iwọ fẹ ododo, iwọ korira ìwa-buburu:
nitori na li Ọlọrun, Ọlọrun rẹ, ṣe fi àmi
ororo ayọ̀ yà ọ ṣolori awọn ọ̀gba rẹ.
8 Gbogbo aṣọ rẹ li o nrun turari, ati
aloe, ati kassia, lati inu ãfin ehin-erin jade
ni nwọn gbe nmu ọ yọ̀.
9 Awọn ọmọbirin awọn alade wà ninu
awọn ayanfẹ rẹ: li ọwọ ọtún rẹ li ayaba na
gbe duro ninu wura Ofiri.
10 Dẹti silẹ, ọmọbirin, si ronu, si dẹ eti
rẹ silẹ! gbagbe awọn enia rẹ, ati ile baba rẹ!
11 Bẹ̃li Ọba yio fẹ ẹwà rẹ gidigidi: ni-
tori on li Oluwa rẹ; ki iwọ ki o si ma sìn i.
12 Ọmọbirin Tire ti on ti ọrẹ; ati awọn
ọlọrọ̀ ninu awọn enia yio ma bẹbẹ oju-rere
rẹ.
13 Ti ogo ti ogo li ọmọbirin ọba na ninu
ile: iṣẹ wura ọnà abẹrẹ li aṣọ rẹ̀.
14 Ninu aṣọ iṣẹ ọnà abẹrẹ li a o mu u
tọ̀ ọba wá: awọn wundia ẹgbẹ rẹ̀ ti ntọ̀ ọ
lẹhin li a o mu tọ̀ ọ wá.
15 Pẹlu inu didùn ati pẹlu ayọ̀ li a o fi
mu wọn wá: nwọn o si wọ̀ ãfin ọba lọ.
16 Nipò awọn baba rẹ li awọn ọmọ rẹ
yio wà, ẹniti iwọ o ma fi jẹ oye lori ilẹ
gbogbo.
17 Emi o ma ṣe orukọ rẹ ni iranti ni
iran gbogbo: nitorina li awọn enia yio ṣe
ma yìn ọ lai ati lailai.

## ORIN 46.

ỌLỌRUN li àbo wa ati agbara, lọwọlọwọ
iranlọwọ ni igba ipọnju.
2 Nitorina li awa ki yio bẹru, bi a tilẹ
ṣi aiye ni idi, ti a si ṣi awọn òke nla nipò
lọ si inu okun:
3 Bi omi rẹ̀ tilẹ nho ti o si nru, bi awọn
òke nla tilẹ nmì nipa ọwọ bibì rẹ̀.
4 Odò nla kan wà, ṣiṣan eyiti yio mu
inu ilu Ọlọrun dùn, ibi mimọ́ agọ wọnni ti
Ọga-ogo.
5 Ọlọrun mbẹ li arin rẹ̀; a ki yio ṣi i ni
idi: Ọlọrun yio ràn a lọwọ ni kutukutu
owurọ.
6 Awọn keferi nbinu, awọn ilẹ ọba ṣidi:
o fọhun rẹ̀, aiye yọ́.
7 Oluwa awọn ọmọ-ogun wà pẹlu wa;
Ọlọrun Jakobu li àbo wa.
8 Ẹ wá wò awọn iṣẹ Oluwa, iru ahoro ti
o ṣe ni aiye.
9 O mu ọ̀tẹ tan de opin aiye; o ṣẹ́ ọrun,
o si ke ọ̀kọ meji; o si fi kẹkẹ́ ogun jona.
10 Ẹ duro jẹ, ki ẹ si mọ̀ pe emi li Ọlọrun,
a o gbé mi ga ninu awọn keferi, a o gbé mi
ga li aiye.

Digitized by Google

11 Oluwa awọn ọmọ-ogun wà pẹlu wa ;
Ọlọrun Jakobu li àbo wa.

## ORIN 47.

ENYIN enia gbogbo, ẹ ṣapẹ ; ẹ fi ohùn
ayọ̀ hó ihó iṣẹgun si Ọlọrun.
2 Nitori Oluwa Ọga-ogo muna ; on li
Ọba nla lori ilẹ-aiye gbogbo.
3 On ni yio ṣẹ́ awọn enia labẹ wa, ati
awọn orilẹ-ède li atẹlẹsẹ wa.
4 On ni yio yàn ilẹ-ini wa fun wa, ọlá
Jakobu, ẹniti o fẹ.
5 Ọlọrun gòke lọ ti on ti ariwo, Oluwa
ti on ti iró ipè.
6 Ẹ kọrin iyìn si Ọlọrun, ẹ kọrin iyìn :
ẹ kọrin iyìn si Ọba wa, ẹ kọrin iyìn.
7 Nitori Ọlọrun li Ọba gbogbo aiye : ẹ fi
oye kọrin iyìn.
8 Ọlọrun jọba awọn keferi : Ọlọrun joko
lori itẹ ìwa-mimọ́ rẹ̀.
9 Awọn alade awọn enia kó ara wọn jọ,
ani awọn enia Ọlọrun Abrahamu : nitori
asà aiye ti Ọlọrun ni : on li a gbe leke jọjọ.

## ORIN 48.

ENI-NLA ni Oluwa, ti a yìn pupọpupọ,
ni ilu Ọlọrun wa, li òke ìwa-mimọ́ rẹ̀.
2 Didara ni ipò itẹdo, ayọ̀ gbogbo aiye
li òke Sioni, ni iha ariwa, ilu Ọba nla.
3 A mọ̀ Ọlọrun li àbo ninu ãfin rẹ̀.
4 Sa wò o, awọn ọba pejọ pọ̀, nwọn
jumọ nkọja lọ.
5 Nwọn ri i, bẽli ẹnu yà wọn ; a yọ wọn
lẹnu, nwọn yara lọ.
6 Ẹru bà wọn nibẹ, ati irora bi obirin ti
nrọbi.
7 Iwọ fi ẹfufu ila-õrun fọ́ ọkọ Tarṣiṣi.
8 Bi awa ti gbọ́, bẽli awa ri ni ilu Oluwa
awọn ọmọ-ogun, ni ilu Ọlọrun wa : Ọlọrun
yio gbé e kalẹ lailai.
9 Awa ti nrò ti iṣeun-ifẹ rẹ, Ọlọrun, li
arin tempili rẹ.
10 Ọlọrun, gẹgẹ bi orukọ rẹ, bẽni iyìn rẹ
de opin aiye : ọwọ ọtún rẹ kún fun ododo.
11 Ki òke Sioni ki o yọ̀, ki inu awọn
ọmọbirin Juda ki o dùn, nitori idajọ rẹ.
12 Rìn Sioni kiri, ki o si yi i ka : kà
ile-iṣọ rẹ̀.
13 Kiyesi odi rẹ̀, kiyesi ãfin rẹ̀ wọnni ;
ki ẹnyin le ma wi fun iran atẹle nyin.
14 Nitori Ọlọrun yi Ọlọrun wa ni lai ati
lailai : on ni yio ma ṣe amọna wa titi ikú.

## ORIN 49.

EGBỌ́ eyi, gbogbo enia ; ẹ fi eti si i,
gbogbo ẹnyin araiye :
2 Ati awọn ọmọ-ẹhin, ati awọn ẹni-ọlọlá,
awọn ọlọrọ̀, ati awọn talaka pẹlu.
3 Ẹnu mi yio sọ̀rọ ọgbọ́n, ati iṣaro aiya
mi yio jẹ oye.
4 Emi o dẹ eti mi silẹ si owe : emi o ṣi
ọ̀rọ ìkọkọ mi silẹ loju okùn dùru.
5 Ēṣe ti emi o fi bẹ̀ru li ọjọ ibi, nigbati
ẹ̀ṣẹ awọn ajinilẹsẹ mi yi mi ka.
6 Awọn ti o gbẹkẹle ọrọ̀ wọn, ti nwọn si
nṣe ileri li ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ wọn ;
7 Kò si ẹnikan, bi o ti wù ki o ṣe, ti o
le rà arakọnrin rẹ̀, bẽni kò le san owo-ira-
pada fun Ọlọrun nitori rẹ̀.
8 Nitori irapada ọkàn wọn iyebiye ni, o
si dẹkun lailai :
9 Nipe ki o fi ma wà lailai, ki o má ṣe
ri isa-okú.
10 Nitori o nri pe awọn ọlọgbọ́n nkú,
bẽli aṣiwere ati ẹranko enia nṣegbe, nwọn
si nfi ọrọ̀ wọn silẹ fun ẹlomiran.
11 Ìro inu wọn ni, ki ile wọn ki o pẹ
titi lai, ati ibujoko wọn lati irandiran ;
nwọn sọ ilẹ wọn nipa orukọ'ara wọn.
12 Ṣugbọn enia ti o wà ninu ọlá kò duro
pẹ : o dabi ẹranko ti o ṣegbe.
13 Ipa ọ̀na wọn yi ni igbẹkẹle wọn : ọ̀rọ
wọn si tọ́ li oju awọn ọmọ wọn.
14 Bi agutan li a ntẹ wọn si isa-okù :
ikú yio jẹun lara wọn ; ẹni diduro-ṣinṣin
ni yio jọba wọn li owurọ ; ẹwà wọn yio si
rẹ̀ kuro, isa-okú si ni ibugbe wọn.
15 Ṣugbọn Ọlọrun ni yio rà ọkàn mi
lọwọ isa-okú : nitoripe on o gbà mi.
16 Iwọ máṣe bẹ̀ru, nitori ẹnikan di ọlọrọ̀,
nitori iyìn ile rẹ̀ npọ̀ si i.
17 Nitoripe, igbati o ba kú, kì yio ko
ohun kan lọ : ogo rẹ̀ kì yio sọkalẹ tọ̀ ọ
lẹhin lọ.
18 Nigbati o wà lãye bi o tilẹ nsure fun
ọkàn ara rẹ̀ : ti awọn enia nyìn ọ, nigbati
iwọ nṣe rere fun ara rẹ.
19 Ọkàn yio lọ si ọdọ iran awọn baba
rẹ̀ ; nwọn kì yio ri imọlẹ lailai.
20 Ọkọnrin ti o wà ninu ọlá, ti kò moye,
o dabi ẹranko ti o ṣegbe.

## ORIN 50.

ỌLỌRUN Olodumare, ani Oluwa li o ti
sọ̀rọ, o si pè aiye lati ìla-õrun wá titi o
fi de ìwọ rẹ̀.
2 Lati Sioni wá, pipé ẹwà, Ọlọrun ti tan
imọlẹ.
3 Ọlọrun wa mbọ̀, kì yio si dakẹ ; iná
yio ma jó niwaju rẹ̀, ẹfufu lile yio si ma ja
yi i ka kiri.
4 Yio si kọ si awọn ọrun lati òke wá,

Digitized by Google

ati si aiye, ki o le ma ṣe idajọ awọn enia
rẹ̀.
5 Kó awọn enia mimọ́ mi jọ pọ̀ si ọdọ
mi: awọn ti o fi ẹbọ ba mi da majẹmu.
6 Awọn ọrun yio si sọ̀rọ ododo rẹ̀: nito-
ri Ọlọrun tikararẹ̀ li onidajọ.
7 Ẹ gbọ́, enyin enia mi, emi o si sọ̀rọ;
Israeli, emi o si jẹri si ọ: emi li Ọlọrun,
ani Ọlọrun rẹ.
8 Emi kì yio ba ọ wi nitori ẹbọ rẹ, ọrẹ-
ẹbọ sisun rẹ wà niwaju mi nigba-gbogbo.
9 Emi kì yio mu akọ-malu lati ile rẹ
jade, tabi obukọ ninu agbo-ẹran rẹ:
10 Nitori gbogbo ẹran igbo ni ti emi,
ati ẹrankẹran lori ẹgbẹrun òke.
11 Emi mọ̀ gbogbo ẹiyẹ awọn òke nla:
ati ẹranko igbẹ ni ti emi.
12 Bi ebi npa mi, emi kì yio sọ fun ọ:
nitori pe aiye ni ti emi, ati ẹkún inu rẹ̀.
13 Emi o ha jẹ ẹran malu, tabi emi a
ma mu ẹ̀jẹ ewurẹ bi?
14 Ru ẹbọ-ọpẹ si Ọlọrun, ki o si san ẹjẹ́
rẹ fun Ọga-ogo.
15 Ki o si kepè mi li ọjọ ipọnju: emi o
gbà ọ, iwọ o si ma yìn mi logo.
16 Ṣugbọn Ọlọrun wi fun enia buburu
pe, Kini iwọ ni ifi ṣe lati ma sọ̀rọ ilana mi,
tabi ti iwọ fi nmu majẹmu mi li ẹnu rẹ?
17 Wò o, iwọ sa korira ẹkọ́, iwọ si ti ṣá
ọ̀rọ mi tì lẹhin rẹ.
18 Nigbati iwọ ri olè, nigbana ni iwọ ba
a mọ̀ ọ pọ̀, iwọ si ba awọn àgbere ṣe ajọpin.
19 Iwọ fi ẹnu rẹ fun buburu, ati ahọn rẹ
npete ẹ̀tan.
20 Iwọ joko, iwọ si sọ̀rọ si arakọnrin rẹ:
iwọ mba orukọ ọmọ iya rẹ jẹ.
21 Nkan wọnyi ni iwọ ṣe, emi si dakẹ;
iwọ ṣebi emi tilẹ dabi iru iwọ tikararẹ:
emi o ba ọ wi, emi o si kà wọn li ẹsẹ-ẹsẹ li
oju rẹ.
22 Njẹ rò eyi, ẹnyin ti o gbagbe Ọlọrun,
ki emi ki o má ba fà nyin ya pẹrẹ-pẹrẹ, ti
kò si olugbala.
23 Ẹnikẹni ti o ba ru ẹbọ iyìn, o yìn mi
logo: ati ẹniti o ba mu ọ̀na ọ̀rọ rẹ̀ tọ́ li emi
o fi igbala Ọlọrun hàn fun.

## ORIN 51.

*Orin Dafidi, nigbati Natani, woli, tọ̀ ọ wá lẹhin ọ̀ran Batṣeba.*

ỌLỌRUN, ṣãnu fun mi, gẹgẹ bi iṣeun ifẹ
rẹ: gẹgẹ bi ìrọnu ọ̀pọ ãnu rẹ, nù ire-
kọja mi nù kuro.
2 Wẹ̀ mi li awẹmọ́ kuro ninu aiṣedede
mi, ki o si wẹ̀ mi nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ mi.
3 Nitori ti mo jẹwọ irekọja mi: nigba-
gbogbo li ẹ̀ṣẹ mi si mbẹ niwaju mi.
4 Iwọ, iwọ nikanṣoṣo ni mo ṣẹ̀ si, ti mo
ṣe buburu yi niwaju rẹ: ki a le da ọ lare,
nigbati iwọ ba nsọ̀rọ, ki ara rẹ ki o le mọ́,
nigbati iwọ ba nṣe idajọ.
5 Kiyesi i, ninu aiṣedede li a gbe bi mi:
ati ninu ẹ̀ṣẹ ni iya mi si loyun mi.
6 Kiyesi i, iwọ fẹ otitọ ni inu: ati niha
ìkọkọ ni iwọ o mu mi mọ̀ ọgbọ́n.
7 Fi ewe-hissopu fọ̀ mi, emi o si mọ́:
wẹ̀ mi, emi o si fún jù ẹ̀gbọn-owu lọ.
8 Mu mi gbọ́ ayọ̀ ati inu didùn; ki
awọn egungun ti iwọ ti rún ki o le ma
yọ̀.
9 Pa oju rẹ mọ́ kuro lara ẹ̀ṣẹ mi, ki iwọ
ki o si nù gbogbo aiṣedede mi nù kuro.
10 Da aiya titun sinu mi, Ọlọrun; ki o
si tún ọkàn diduro-ṣinṣin ṣe sinu mi.
11 Máṣe ṣa mi tì kuro niwaju rẹ; ki o
má si ṣe gbà Ẹmi mimọ́ rẹ lọwọ mi.
12 Mu ayọ̀ igbala rẹ pada tọ̀ mi wá; ki
o si fi ẹmi omnira rẹ gbé mi duro.
13 Nigbana li emi o ma kọ́ awọn olure-
kọja li ọ̀na rẹ: awọn ẹlẹṣẹ yio si ma yipada
si ọ.
14 Ọlọrun, gbà mi lọwọ ẹbi ẹ̀jẹ, iwọ
Ọlọrun igbala mi: ahọn mi yio si ma kọrin
ododo rẹ kikan.
15 Oluwa, iwọ ṣi mi li ète; ẹnu mi yio
si ma fi iyìn rẹ han:
16 Nitori iwọ kò fẹ ẹbọ, ti emi iba ru u:
inu rẹ kò dùn si ọrẹ-ọbọ sisun.
17 Ẹbọ Ọlọrun ni irobinujẹ ọkàn: iro-
binujẹ ati irora aiya, Ọlọrun, on ni iwọ kì
yio gàn.
18 Ṣe rere ni didùn inu rẹ si Sioni: iwọ
mọ odi Jerusalemu.
19 Nigbana ni inu rẹ yio dùn si ẹbọ
ododo; pẹlu ọrẹ-ẹbọ sisun ati ọ̀tọtọ ọrẹ-ẹbọ
sisun: nigbana ni nwọn o fi akọ-malu rubọ
lori pẹpẹ rẹ.

## ORIN 52.

*Orin Dafidi, nigbati Doegi, ara Edomu, wá, ti o sọ fun Saulu, ti o si wi fun u pe, Dafidi wa si ile Ahimeleki.*

EṢE ti iwọ fi nṣe-fefe ninu ìwa-ìka, iwọ
alagbara ọkọnrin? ore Ọlọrun duro pẹ
titi.
2 Ahọn rẹ ngbiro ìwa-ìka; bi abẹ mimú
o nṣiṣẹ ẹ̀tan.
3 Iwọ fẹ ibi jù ire lọ; ati eke jù ati sọ
ododo lọ.
4 Iwọ fẹ ọ̀rọ ipanirun gbogbo, iwọ ahọn
ẹ̀tan.

Digitized by Google

Ọlọrun yio si lù ọ bolẹ lailai, yio si dì
., yio si ja ọ kuro ni ibujoko rẹ, yio si
tu kuro lori ilẹ alãye.
Olododo yio ri i pẹlu, yio si bẹ̀ru, yio
a rẹrin rẹ̀ : pe,
Kiyesi ọkọnrin ti kò fi Ọlọrun ṣe agba-
ẹ̀ ; bikoṣe li ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ rẹ̀ li o gbẹkẹle,
mu ara rẹ̀ le ninu ìwa-buburu rẹ̀.
Ṣugbọn emi dabi igi olifi tutu ni ile
run : emi gbẹkẹle ãnu Ọlọrun lai ati
ai.
9 Emi o ma yìn ọ lailai nitoripe iwọ li o
e : emi o si ma duro de orukọ rẹ ; nitori
o dara li oju awọn enia mimọ́ rẹ.

## ORIN 53.

ṢIWERE wi li ọkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun kò si.
1 Nwọn bajẹ nwọn si nṣe irira ẹ̀ṣẹ: kò
. ẹniti o nṣe rere.
2 Ọlọrun bojuwo ilẹ lati ọrun wá sara
awọn ọmọ ẹnia, lati wò bi ẹnikan wà ti oye
re, ti o si nwá Ọlọrun.
3 Gbogbo wọn li o si pada sẹhin, nwọn
si di elẽri patapata : kò si ẹniti nṣe rere,
kò si ẹnikan.
4 Awọn ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ, ko ha ni ìmọ ? awọn
ẹniti njẹ ẹnia mi bi ẹni jẹun: nwọn kò si
kepe Ọlọrun.
5 Nibẹ ni nwọn gbe wà ni ibẹ̀ru nla ni-
biti ẹ̀ru kò gbe si : nitori Ọlọrun ti fún
egungun awọn ti o dótì ọ ka : iwọ ti dojutì
wọn, nitori Ọlọrun ti kẹgàn wọn.
6 Tani yio fi igbala fun Israeli lati Sioni
jade wá ? Nigbati Ọlọrun ba mu igbekun
awọn enia rẹ̀ pada wá, Jakobu yio yọ̀, inu
Israeli yio si dùn.

## ORIN 54.

*Orin Dafidi, nigbati awọn ara Sifi wá, ti nwọn si sọ fun Saulu pe, Dafidi fi ara rẹ̀ pamọ lọdọ wa.*

ỌLỌRUN gbà mi nipa orukọ rẹ, si ṣe
idajọ mi nipa agbara rẹ.
2 Gbọ́ adura mi, Ọlọrun ; fi eti si ọ̀rọ
ẹnu mi.
3 Nitoriti awọn alejò dide si mi, awọn
aninilara si nwá ọkàn mi : nwọn kò kà
Ọlọrun si li oju wọn.
4 Kiyesi i, Ọlọrun li oluranlọwọ mi :
Oluwa wà pẹlu awọn ti o gbé ọkàn mi duro.
5 Yio si fi ibi san a fun awọn ọta mi : ke
wọn kuro ninu otitọ rẹ.
6 Emi o rubọ atinuwa si ọ : Oluwa, emi
o yìn orukọ rẹ ; nitoriti o dara.
7 Nitori o ti yọ mi kuro ninu iṣẹ́ gbo-
gbo : oju mi si ri ifẹ rẹ̀ lara awọn ọta mi.

## ORIN 55.

FETI si adura mi, Ọlọrun ; má si ṣe fi
ara rẹ pamọ kuro ninu ẹ̀bẹ mi.
2 Fiye si mi, ki o si da mi lohùn : ara
mi kò lelẹ ninu aroye mi, emi si npariwo ;
3 Nitori ohùn ọta nì, nitori inilara enia
buburu : nitoriti nwọn mu ibi ba mi, ati
ni ibinu nwọn dẹkun fun mi.
4 Aiya dùn mi gidigidi ninu mi : ipaiya
ikú si ṣubu lù mi.
5 Ibẹ̀ru ati ìwariri wá si ara mi, ati
ibẹ̀ru ikú bò mi mọlẹ.
6 Emi si wipe, A ! iba ṣe pe emi ni iyẹ-
apa bi àdaba ! emi iba fò lọ, emi a si simi.
7 Kiyesi i, emi iba rìn lọ si ọ̀na jijin
réré, emi a si ma gbe li aginju.
8 Emi iba yara sa asala mi kuro ninu
ẹfufu lile ati iji na.
9 Oluwa, ṣe iparun, ki o si yà wọn li
ahọn : nitori ti mo ri ìwa agbara ati ijà ni
ilu na.
10 Ọsan ati oru ni nwọn fi nrìn odi rẹ̀
kiri : ìwa-ika pẹlu ati ikãnu mbẹ li arin rẹ̀.
11 Ìwa buburu mbẹ li arin rẹ̀ : ẹ̀tan ati
eke kò kuro ni igboro rẹ̀.
12 Nitoriti kì iṣe ọta li o gàn mi : njẹ
emi iba pa a mọra : bẽni kì iṣe ẹniti o
korira mi li o gbé ara rẹ̀ ga si mi ; njẹ emi
iba fi ara mi pamọ́ kuro lọdọ rẹ̀ :
13 Ṣugbọn iwọ ni, ọkọnrin ọ̀gba mi,
amọ̀na mi, ati ojulumọ mi.
14 Awa jumọ gbimọ didùn, awa si kẹgbẹ
rìn wọ̀ ile Ọlọrun lọ.
15 Ki ikú ki o dì wọn mu, ki nwọn ki
o si lọ lãye si isa-okú : nitori ti ìwa-buburu
mbẹ ni ibujoko wọn, ati ninu wọn.
16 Bi o ṣe ti emi ni, emi o kepè Ọlọrun ;
Oluwa yio si gbà mi.
17 Li alẹ, li owurọ, ati li ọsan, li emi o
ma gbadura, ti emi o si ma kigbe kikan :
on o si gbohùn mi.
18 O ti gbà ọkàn mi silẹ li alafia lọwọ
ogun ti o ti dò tì mi : nitoripe pẹlu ọ̀pọlọpọ
enia ni nwọn dide si mi.
19 Ọlọrun yio gbọ́, yio si pọ́n wọn loju,
ani ẹniti o ti joko lati igbani. Nitoriti
nwọn kò ni ayipada, nwọn kò si bẹ̀ru
Ọlọrun.
20 O ti nà ọwọ rẹ̀ si iru awọn ti o wà li
alafia pẹlu rẹ̀ : o ti dà majẹmu rẹ̀.
21 Ọrọ ẹnu rẹ̀ kunna jù ori-amọ lọ,
ṣugbọn ogun jija li o wà li aiya rẹ̀ : ọ̀rọ rẹ̀
kunna jù ororo lọ, ṣugbọn idà fifayọ ni
nwọn.
22 Kó ọrù rẹ lọ si ara Oluwa, on ni yio

Digitized by Google

si mu ọ duro: on kì yio jẹ ki ẹsẹ olododo
ki o yẹ̀ lai.
23 Ṣugbọn iwọ, Ọlọrun, ni yio mu wọn
sọkalẹ lọ si iho iparun: awọn enia ẹ̀jẹ ati
enia ẹ̀tan kì yio pe àbọ ọjọ wọn; ṣugbọn
emi o gbẹkẹle ọ.

## ORIN 56.

*Orin Dafidi, nigbati awọn ara Filistia mu u ni Gati.*

ỌLỌRUN, ṣãnu fun mi: nitoriti enia nfẹ
gbe mi mì; o mba mi jà lojojumọ, o
nni mi lara.
2 Awọn ọta mi nfẹ igbe mi mì lojojumọ:
nitori awọn ti nfi igberaga ba mi ja pọ̀.
3 Nigbati ẹ̀ru ba mbà mi, emi o gbẹ-
kẹle ọ.
4 Nipa Ọlọrun li emi o ma yìn ọ̀rọ rẹ̀,
Ọlọrun li emi o gbẹkẹ mi le, emi kì yio
bẹ̀ru: kili ẹran-ara le ṣe si mi.
5 Lojojumọ ni nwọn nlọ́ ọ̀rọ mi: ibi ni
gbogbo ìro inu wọn si mi:
6 Nwọn kó ara wọn jọ, nwọn ba, nwọn
kiyesi ìrin mi, nwọn ti nṣọ̀na ọkàn mi.
7 Nwọn ha le ti ipa aiṣedede là? ni ibinu
wọ́ awọn enia na jatilẹ, Ọlọrun.
8 Iwọ nka ìrin-kiri mi: fi omije mi sinu
igo rẹ: nwọn ko ha si ninu iwe rẹ bi?
9 Li ọjọ ti mo ba kigbe, nigbana li awọn
ọta mi yio pẹhinda: eyi li emi mọ̀: nito-
ripe Ọlọrun wà fun mi.
10 Nipa Ọlọrun li emi o ma yìn ọ̀rọ rẹ̀:
nipa Oluwa li emi o ma yìn ọ̀rọ rẹ̀.
11 Ọlọrun li emi gbẹkẹ mi le, emi kì yio
bẹ̀ru kili enia le ṣe si mi.
12 Ẹjẹ́ rẹ mbẹ lara mi, Ọlọrun: emi o
fi iyìn fun ọ.
13 Nitoripe iwọ li o ti gbà ọkàn mi lọwọ
ikú: iwọ ki yio ha gbà ẹsẹ mi lọwọ iṣubu?
ki emi ki o le ma rìn niwaju Ọlọrun ni
imọlẹ awọn alãye?

## ORIN 57.

*Orin Dafidi, nigbati o sa kuro lọwọ Saulu sinu iho-okuta.*

SÃNU fun mi: Ọlọrun, sãnu fun mi:
nitoriti ọkàn mi gbẹkẹle ọ: lõtọ, li
ojiji iyẹ-apa rẹ li emi o fi ṣe àbo mi, titi
wahala wọnyi yio fi rekọja.
2 Emi o kigbe pe Ọlọrun Ọga-ogo; si
Ọlọrun ti o ṣe ohun gbogbo fun mi.
3 On o ranṣẹ lati ọrun wá, yio si gbà
mi bi ẹniti nfẹ gbe mi mì tilẹ nkẹgàn mi.
Ọlọrun yio rán ãnu rẹ̀ ati otitọ rẹ̀ jade.
4 Ọkàn mi wà lãrin awọn kiniun: emi
tilẹ dubulẹ lãrin awọn ti o gbiná, eyinì ni
awọn ọmọ enia, ehín ẹniti iṣe ọ̀kọ ati ọfa,
ati ahọn wọn idà mimú.
5 Gbigbe-ga ni ọ, Ọlọrun, jù ọrun lọ;
ati ogo rẹ jù gbogbo aiye lọ.
6 Nwọn ti ta àwọn silẹ fun ẹsẹ mi:
nwọn tẹ ori ọkàn mi ba: nwọn ti wà iho
silẹ niwaju mi, li ãrin eyina li awọn tika-
rawọn jìn si.
7 Ọkàn mi ti mura, Ọlọrun, ọkàn mi ti
mura: emi o kọrin, emi o si ma kọrin
iyìn.
8 Jí, iwọ ogo mi; jí, ohun-èlo orin ati
duru: emi tikarami yio si jí ni kutukutu.
9 Emi o ma yìn ọ, Oluwa lãrin awọn
enia: emi o si ma kọrin si ọ lãrin awọn
orilẹ-ède.
10 Nitoriti ãnu rẹ pọ̀ de ọrun, ati otitọ
rẹ de awọsanma.
11 Gbigbe-ga ni ọ Ọlọrun, jù awọn ọrun
lọ ati ogo rẹ jù gbogbo aiye lọ.

## ORIN 58.

ẸNYIN ha nsọ ododo nitõtọ, ẹnyin ijọ
enia? ẹnyin ha nṣe idajọ ti o ṣe titọ,
ẹnyin ọmọ enia?
2 Nitõtọ, ẹnyin nṣiṣẹ buburu li aiya:
ẹnyin nwọ̀n ìwa-agbara ọwọ nyin li aiye.
3 Lati inu iya wọn wá li awọn enia bu-
buru ti ṣe iyapa: nwọn ti ṣina lojukanna
ti a ti bi wọn, nwọn a ma ṣeke.
4 Oró wọn dabi oró ejò: nwọn dabi
aditi ejò pamọlẹ ti o di ara rẹ̀ li eti;
5 Ti kò fẹ igbọ́ ohùn awọn atuniloju, bi
o ti wù ki o ma fi ọgbọ́n ṣe ituju to.
6 Ká wọn li ehin, Ọlọrun, li ẹnu wọn:
ká ọ̀gan awọn ọmọ kiniun nì, Oluwa.
7 Ki nwọn ki o yọ́ danu bi omi ti nṣàn
nigbagbogbo: nigbati o ba fa ọrun lati tafà
rẹ̀, ki nwọn ki o dabi ẹnipe a ke wọn ni
ijanja.
8 Bi igbín ti a tẹ̀ rẹ́ ti o si ṣegbe: bi
iṣẹnu obirin, bẽni ki nwọn ki o má ṣe ri
õrùn.
9 Ki ikoko nyin ki o to mọ̀ igbona ẹgùn,
iba tutu iba ma jo, yio fi iji gbà wọn lọ.
10 Olododo yio yọ̀ nigbati o ba ri ẹsan
na: yio si wẹ̀ ẹsẹ rẹ̀ ninu ẹ̀jẹ awọn enia
buburu.
11 Bẹ̃li enia o si wipe, Lõtọ, ère mbẹ
fun olododo: lõtọ, on li Ọlọrun ti o nṣe
idajọ ni aiye.

Digitized by Google

## ORIN 59.

*Orin Dafidi, nigbati Saulu ranșę, ti nwọn si nșọ ile lati pa a.*

OLỌRUN mi, gbà mi lọwọ awọn ọta mi:
dābobo mi lọwọ awọn ti o dide si mi.
2 Gbà mi lọwọ awọn onișẹ ẹ̀ṣẹ, ki o si
gbà mi silẹ lọwọ awọn enia-ẹ̀jẹ.
3 Sa kiyesi i, nwọn ba ni buba fun ọkàn
mi, awọn alagbara pejọ si mi; kì ișe nitori
irekọja mi, tabi nitori ẹ̀ṣẹ mi, Oluwa.
4 Nwọn sure, nwọn mura li aișẹ mi:
dide lati pade mi, ki o si kiyesi i.
5 Nitorina iwọ, Oluwa, Ọlọrun awọn
ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, jí lati bẹ̀ gbogbo
awọn keferi wò; máșe șãnu fun olurekọja
buburu wọnni.
6 Nwọn pada li aṣalẹ: nwọn npariwo bi
ajá, nwọn nrìn yi ilu na ka.
7 Kiyesi i, nwọn nfi ẹnu wọn gùfẹ jade:
idà wà li ète wọn: nitoriti nwọn nwipe,
tali o gbọ́?
8 Șugbọn iwọ, Oluwa, yio rẹrin wọn:
iwọ ni yio yọșuti si gbogbo awọn keferi.
9 Agbara rẹ̀ li emi o duro tì: nitori
Ọlọrun li àbo mi.
10 Ọlọrun ãnu mi ni yio șaju mi:
Ọlọrun yio jẹ ki emi ri ifẹ mi lara awọn
ọta mi.
11 Máșe pa wọn, ki awọn enia mi ki o
má ba gbagbe: tú wọn ká nipa agbara rẹ;
ki o si sọ̀ wọn kalẹ, Oluwa asà wa.
12 Nitori ẹ̀ṣẹ ẹnu wọn ni ọ̀rọ ète wọn,
ki a mu wọn ninu igberaga wọn: ati nitori
ẽbu ati èke ti nwọn nșe.
13 Run wọn ni ibinu, run wọn, ki nwọn
ki o má șe si mọ́: ki o si jẹ ki nwọn ki
o mọ̀ pe, Ọlọrun li olori ni Jakobu titi o
fi de opin aiye.
14 Ati li aṣalẹ jẹ ki nwọn ki o pada;
ki nwọn ki o pariwo bi ajá, ki nwọn ki o
si ma yi ilu na ka kiri.
15 Jẹ ki nwọn ki o ma rìn soke rìn sodò
fun ohun jijẹ, bi nwọn kò ba yó, nwọn o
duro ni gbogbo oru na.
16 Șugbọn emi o kọrin agbara rẹ; ni-
tõtọ, emi o kọrin ãnu rẹ kikan li owurọ:
nitori pe iwọ li o ti nșe àbo ati ibi-asala
mi li ọjọ ipọnju mi.
17 Iwọ, agbara mi, li emi o kọrin si:
nitori Ọlọrun li àbo mi, Ọlọrun ãnu mi!

## ORIN 60.

*Orin Dafidi, nigbati o mba awọn ara Siria ti o wà larin odò meji, ati awọn ara Siria ti Soba ja, nigbati Joabu pada, ti o si pa ẹgbãfa ninu awọn ara Edomu li afonifoji iyọ̀.*

OLỌRUN, iwọ ti șa wa tì, iwọ ti tú wa
ka, inu rẹ ti bajẹ; tún ara rẹ yipada
si wa.
2 Iwọ ti mu ilẹ warìri; iwọ ti fọ ọ: mu
fifọ rẹ̀ bọ̀ sipò: nitoriti o nmì.
3 Iwọ ti fi ohun ti o șoro hàn awọn enia
rẹ: iwọ ti mu wa mu ọti-waini itagbọn-
gbọn.
4 Iwọ ti fi ọpagun fun awọn ti o bẹ̀ru
rẹ, ki a le ma fi i hàn nitori otitọ.
5 Ki a le gbà awọn olufẹ rẹ là; fi ọwọ
ọtún rẹ șe igbala, ki o si gbohùn mi.
6 Ọlọrun ti sọ̀rọ ninu ìwa-mimọ́ rẹ̀ pe;
Emi o yọ̀, emi o pin Șekemu, emi o si
wọ̀n afonifoji Sukkotu.
7 Ti emi ni Gileadi, ti emi ni Manasse;
Efraimu pẹlu li agbara ori mi; Juda li
olofin mi;
8 Moabu li ikoko-iwẹsẹ mi; lori Edomu
li emi o bọ́ bàta mi si: Filistia ma ho iho
ayọ̀ fun mi!
9 Tani yio mu mi wá sinu ilu olodi nì?
tani yio sin mi lọ si Edomu?
10 Iwọ ha kọ́, Ọlọrun, ẹniti o șa wa tì?
ati iwọ, Ọlọrun, ti kò ba ogun wa jade lọ?
11 Fun wa ni iranlọwọ ninu ipọnju:
nitori pe asan ni iranlọwọ enia.
12 Nipasẹ Ọlọrun li awa o șe aki: nitori
on ni yio tẹ̀ awọn ọta wa mọlẹ.

## ORIN 61.

GBỌ ẹkún mi, Ọlọrun; fiye si adura mi.
2 Lati opin aiye wá li emi o kigbe
pè ọ, nigbati o rẹ̀ aiya mi: fà mi lọ si
apata ti o ga jù mi lọ.
3 Nitori iwọ li o ti nșe àbo fun mi, ati
ile-ișọ agbara lọwọ ọta nì.
4 Emi o joko ninu agọ rẹ lailai: jẹ ki
emi ri àbo ni iyẹ-apa rẹ.
5 Nitoripe iwọ, Ọlọrun, li o ti gbọ́ ẹjẹ́
mi: iwọ ti fi ogún awọn ti o bẹ̀ru orukọ rẹ
fun mi.
6 Iwọ o fa ẹmi ọba gùn: ati ọjọ ọdun
rẹ̀ bi atiran-diran.
7 On o ma gbe iwaju Ọlọrun lailai;
pèse ãnu ati otitọ, ti yio ma șe itọju rẹ̀.
8 Bẹ̃li emi o ma kọrin iyìn si orukọ rẹ
lailai, ki emi ki o le ma san ẹjẹ́ mi li
ojojumọ.

## ORIN 62.

OLỌRUN nikan li ọkàn mi duro jẹ dè;
lati ọdọ rẹ̀ wá ni igbala mi.

Digitized by Google

2 On nikan li apata mi ati igbala mi;
on li àbo mi; emi kì yio şipo pada jọjọ.
3 Ẹnyin o ti ma rọlu enia kan pẹ to?
gbogbo nyin li o fẹ pa a: bi ogiri ti o
bì ati bi ọgbà ti nwó lọ.
4 Kiki ìro wọn ni lati já a tilẹ kuro
ninu ọlá rẹ̀: nwọn nṣe inu didùn ninu
eke: nwọn nfi ẹnu wọn sure, şugbọn nwọn
ngegun ni inu wọn.
5 Ọkàn mi, iwọ sa duro jẹ de Ọlọrun;
nitori lati ọdọ rẹ̀ wá ni ireti mi.
6 On nikan li apata mi ati igbala mi:
on li àbo mi; a kì yio şi mi ni ipò.
7 Nipa Ọlọrun ni igbala mi, ati ogo mi:
apata agbara mi, àbo mi si mbẹ ninu
Ọlọrun.
8 Gbẹkẹle e nigbagbogbo; ẹnyin enia,
tú ọkàn nyin jade niwaju rẹ̀; Ọlọrun li àbo
fun wa.
9 Nitõtọ asan li awọn ọmọ enia, eke si
li awọn oloyè. Nwọn gòke ninu ìwọn,
bakanna ni nwọn fẹrẹ jù asan lọ.
10 Máşe gbẹkẹle inilara, ki o má si şe
gberaga li olè jija: bi ọrọ̀ ba npọ̀ si i, máşe
gbe ọkàn nyin le e.
11 Ọlọrun ti sọ̀rọ lẽkan; lẽrinkeji ni
mo gbọ́ eyi pe: ti Ọlọrun li agbara.
12 Pẹlupẹlu, Oluwa, tirẹ li ãnu: nitoriti
iwọ san a fun olukulùku enia gẹgẹ bi işẹ rẹ̀.

## ORIN 63.

*Orin Dafidi, nigbati o wà li aginju Juda.*

OLỌRUN, iwọ li Ọlọrun mi; ni kutu-
kutu li emi o ma şafẹri rẹ; ongbẹ rẹ
ngbẹ ọkàn mi, ẹran-ara mi fà si ọ ni ilẹ
gbigbẹ, ati ilẹ ti npọngbẹ, nibiti omi kò
gbe si.
2 Bayi li emi ti wò ọ ninu ibi-mimọ́,
lati ri agbara rẹ ati ogo rẹ.
3 Nitori ti işeun-ifẹ rẹ san jù ìye lọ, ète
mi yio ma yìn ọ.
4 Bayi li emi o ma fi ibukún fun ọ
niwọnbi mo ti wà lãye: emi o ma gbé
ọwọ mi soke li orukọ rẹ.
5 Bi ẹnipe ijà ati ọ̀ra bẽni yio tẹ ọkàn
mi lọrun; ẹnu mi yio si ma fi ète ayọ̀ yìn ọ:
6 Nigbati mo ba ranti rẹ lori ẹní mi,
ti emi si nşe aşaro rẹ ni işọ oru.
7 Nitoripe iwọ li o ti nşe iranlọwọ mi,
nitorina li ojiji iyẹ́-apa rẹ li emi o ma yọ̀.
8 Ọkàn mi ntọ̀ ọ lẹhin girigiri: ọwọ
ọtún rẹ li o gbé mi ró.
9 Şugbọn awọn ti nwá ọkàn mi lati pa
a run, nwọn o lọ si iha isalẹ-ilẹ.
10 Nwọn o ti ọwọ idà şubu: nwọn o si
şe ijẹ fun kọ̀lọkọlọ.

11 Şugbọn ọba yio ma yọ̀ ninu Ọlọrun;
olukuluku ẹniti o nfi i bura ni yio şogo:
şugbọn awọn ti nşeke li a o pa li ẹnu mọ́.

## ORIN 64.

OLỌRUN, gbohùn mi ninu aroye mi:
pa ẹmi mi mọ́ lọwọ ẹ̀ru ọta nì.
2 Pa mi mọ́ lọwọ ìmọ ìkọkọ awọn enia
buburu; lọwọ irukerudo awọn onişẹ-ẹ̀şẹ.
3 Ẹniti npọ́n ahọn wọn bi ẹnipe idà, ti
nwọn si fa ọrun wọn le lati tafa wọn, ani
ọ̀rọ kikoro:
4 Ki nwọn ki o le ma tafà ni ìkọkọ si
awọn ti o pé: lojiji ni nwọn tafa si i, nwọn
kò si bẹ̀ru.
5 Nwọn gba ara wọn niyanju li ọ̀ran
buburu: nwọn gbìmọ ati dẹkun silẹ nikọ̀-
kọ; nwọn wipe, Tani yio ri wọn?
6 Nwọn gbero ẹ̀şẹ; nwọn wipe, awa ti
pari ero ti a gbà tan: ati ìro inu olukuluku
wọn, ati aiya wọn, o jinlẹ.
7 Şugbọn Ọlọrun yio tafà si wọn lojiji;
nwọn o si gbọgbẹ.
8 Bẽni ahọn wọn yio mu wọn şubu lu
ara wọn: gbogbo ẹniti o ri wọn yio mì ori
wọn.
9 Ati gbogbo enia ni yio ma bẹ̀ru, nwọn
o si ma sọ̀rọ işẹ Ọlọrun; nitoriti nwọn o fi
ọgbọ́n rò işẹ rẹ̀.
10 Olododo yio ma yọ̀ nipa ti Oluwa,
yio si ma gbẹkẹle e; ati gbogbo ẹni-iduro-
şinşin li aiya ni yio ma şogo.

## ORIN 65.

OLỌRUN, iyìn duro jẹ de ọ ni Sioni: ati
si ọ li a o mu ileri ifẹ nì şẹ.
2 Iwọ ti ngbọ́ adura, si ọdọ rẹ ni gbogbo
enia mbọ̀.
3 Ọ̀ran aişedede bori mi: bí o şe ti
irekọja wa ni, iwọ ni yio wẹ̀ wọn nù kuro.
4 Alabukún-fun li ẹniti iwọ yàn, ti iwọ
si mu lati ma sunmọ ọdọ rẹ, ki o le ma
gbe inu agbala rẹ wọnni: ore inu ile rẹ
yio tẹ́ wa lọrùn, ani ti tempili mimọ́ rẹ.
5 Ohun iyanu nipa ododo ni iwọ fi da
wa lohùn, Ọlọrun igbala wa: ẹniti işe
igbẹkẹle gbogbo opin aiye, ati awọn ti o
jina réré li okun.
6 Nipa agbara rẹ̀ ẹniti o fi idi òke nla
mulẹ şinşin; ti a fi agbara dì li àmure:
7 Ẹniti o pa ariwo okun mọ́ rọrọ, ariwo
riru-omi wọn, ati gìdigidi awọn enia.
8 Awọn pẹlu ti ngbe apa ipẹkun mbẹ̀ru
nitori àmi rẹ wọnni: iwọ mu ijade owurọ
ati ti aşalẹ yọ̀.
9 Iwọ bẹ aiye wò, o si bomi rin i: iwọ

Digitized by Google

ı li ọrọ̀, odò Ọlọrun kún fun omi : iwọ
ọkà wọn, nigbati iwọ ti pèse ilẹ bẽ.
ˈ Iwọ fi irinmi si aporo rẹ̀ pipọpìpọ :
si tẹ́ ogulutu rẹ̀ : iwọ fi ọwọ òjo mu ilẹ
ı : iwọ busi hihu rẹ̀.
. Iwọ fi ore rẹ de ọdun li ade ; ọrá nkán
ıa-ọ̀na rẹ.
! Papa-tutù aginju nkán ; awọn òke
ːke fi ayọ̀ di ara wọn li àmure.
ȝ Agbo ẹran li a fi wọ̀ papa-tutù na li
: afonifoji li a fi ọka bò mọlẹ : nwọn
fun ayọ̀, nwọn nkọrin pẹlu.

## ORIN 66.

HÓ iho ayọ̀ si Ọlọrun, ẹnyin ilẹ gbo-
gbo :
Ẹ kọrin ọlá orukọ rẹ̀ : ẹ mu iyìn rẹ̀ li

Ẹ wi fun Ọlọrun pe, Iwọ ti li ẹ̀ru to
u iṣẹ rẹ ! nipa ọ̀pọ agbara rẹ li awọn
rẹ yio fi ori wọn balẹ fun ọ.
Gbogbo aiye ni yio ma sin ọ, nwọn o
ıa kọrin si ọ ; nwọn o ma kọrin si orukọ

Ẹ wa wò iṣẹ Ọlọrun, o li ẹ̀ru ni iṣe rẹ̀
wọn ọmọ enia.
O sọ okun di ilẹ gbigbẹ : nwọn fi ẹsẹ
ıdò já : nibẹ li awa gbe yọ̀ ninu rẹ̀.
O jọba nipa agbara rẹ̀ lailai ; oju rẹ̀
ò awọn orilẹ-ède : ki awọn ọlọtẹ ki o
ṣe gbé ara wọn ga.
; Ẹ fi ibukún fun Ọlọrun wa, ẹnyin
a, ki ẹ si mu ni gbọ́ ohùn iyìn rẹ̀.
) Ẹniti o mu ẹmi wa wà lãye, ti kò si jẹ
ẹsẹ wa ki o yẹ̀.
10 Ọlọrun, nitori ti iwọ ti ridi wa : iwọ
lan wa wò, bi ã ti idan fadaka wò.
11 Iwọ mu wa wọ̀ inu àwọn ; iwọ fi
ınju le wa li ẹgbẹ.
12 Iwọ mu awọn enia gùn wa li ori : awa
ˈọ inu iná ati omi lọ, ṣugbọn iwọ mu wa
le wá si ibi irọra.
13 Emi o lọ sinu ile rẹ ti emi ti ẹbọ
un : emi o san ẹ̀jẹ́ mi fun ọ,
14 Ti ète mi ti jẹ́, ti ẹnu si ti sọ, nigbati
ɔ wà ninu ipọnju.
15 Emi o ru ẹbọ sisun ọ̀lọra si ọ, pẹlu
ùn ọrá àgbo ; emi o rubọ akọ-malu pẹlu
ˈurẹ.
16 Ẹ wá gbọ́, gbogbo ẹnyin ti o bẹ̀ru
ọrun, emi o sọ ohun ti o ṣe fun ọkàn
i.
17 Emi fi ẹnu mi kigbe pè e, emi o si fi
ıọn mi buyin fun u.
18 Bi emi ba gbà ẹ̀ṣẹ li aiya mi, Oluwa
yio gbohùn mi :
19 Ṣugbọn nitõtọ Ọlọrun ti gbohùn mi :
o si ti fi eti si ohùn adura mi.
20 Olubukún li Ọlọrun, ti kò yi adura
mi pada kuro, tabi ãnu rẹ̀ kuro lọdọ mi.

## ORIN 67.

KI Ọlọrun ki o ṣãnu fun wa, ki o si busi
i fun wa ; ki o si ṣe oju rẹ̀ ki o mọlẹ
si wa lara,
2 Ki ọ̀na rẹ ki o le di mimọ̀ li aiye, ati
igbala ilera rẹ ni gbogbo orilẹ-ède.
3 Jẹ ki awọn enia ki o yìn ọ, Ọlọrun ;
jẹ ki gbogbo enia ki o yìn ọ.
4 Jẹ ki inu awọn orilẹ-ède ki o dùn, ki
nwọn ki o ma kọrin fun ayọ̀ : nitoriti iwọ
o fi ododo ṣe idajọ enia, iwọ o si jọba awọn
orilẹ-ède li aiye.
5 Jẹ ki awọn enia ki o yìn ọ, Ọlọrun ;
jẹ ki gbogbo enia ki o yìn ọ.
6 Nigbana ni ilẹ yio to ma mu asunkún
rẹ̀ wá ; Ọlọrun, Ọlọrun wa tikararẹ̀ yio
busi i fun wa.
7 Ọlọrun yio busi i fun wa ; ati gbogbo
opin aiye yio si ma bẹ̀ru rẹ̀.

## ORIN 68.

KI Ọlọrun ki o dide, ki a si tú awọn ọta
rẹ̀ ka : ki awọn ti o korira rẹ̀ pẹlu, ki
nwọn ki o salọ kuro niwaju rẹ̀.
2 Bi ẽfin ti ifẹ lọ, bẹ̃ni ki o fẹ wọn lọ ;
bi ida ti iyọ́ niwaju iná, bẹ̃ni ki enia bubu-
ru ki o ṣegbe niwaju Ọlọrun.
3 Ṣugbọn jẹ ki inu awọn olododo ki o
dùn ; ki nwọn ki o yọ̀ niwaju Ọlọrun,
nitõtọ, ki nwọn ki o yọ̀ gidigidi.
4 Ẹ kọrin si Ọlọrun, ẹ kọrin iyìn si oru-
kọ rẹ̀ : ẹ la ọ̀na fun ẹniti nrekọja li aginju
nipa JAH, orukọ rẹ̀, ki ẹ si ma yọ̀ niwaju
rẹ̀.
5 Baba awọn alainibaba ati onidajọ awọn
opó, li Ọlọrun ni ibujoko rẹ̀ mimọ́.
6 Ọlọrun mu ẹni-ofo joko ninu ile : o
mu awọn ti a dè li ẹ̀wọn jade wá si irọra :
ṣugbọn awọn ọlọtẹ ni ngbe inu ilẹ gbigbẹ.
7 Ọlọrun, nigbati iwọ jade lọ niwaju
awọn enia rẹ, nigbati iwọ nrìn lọ larin
aginju.
8 Ilẹ mì, ọrun bọ silẹ niwaju Ọlọrun :
ani Sinai tikararẹ̀ mì niwaju Ọlọrun, Ọlọ-
run Israeli.
9 Ọlọrun, iwọ li o rán ọ̀pọlọpọ òjo si ilẹ-
ini rẹ, nigbati o rẹ̀ ẹ tan, iwọ tù u lara.
10 Ijọ enia rẹ li o tẹ̀do sinu rẹ̀ : iwọ
Ọlọrun ninu ore rẹ li o ti pèse fun awọn
talaka.

Digitized by Google

11 Oluwa ti sọ̀rọ: ọ̀pọlọpọ si li ogun awọn ẹniti nfi ayọ̀ rohin rẹ̀:
12 Awọn ọba awọn ẹgbẹ ogun sa, nwọn sa lọ: obirin ti o si joko ni ile ni npin ikogun na.
13 Nigbati ẹnyin dubulẹ larin agbo ẹran, nigbana ni ẹnyin o dabi iyẹ adaba ti a bò ni fadaka, ati ihuhu rẹ̀ pẹlu wura pupa.
14 Nigbati Olodumare tú awọn ọba ká ninu rẹ̀, o dabi òjo-didì ni Salmoni.
15 Òke Ọlọrun li òke Baṣani: òke ti o ni ori pupọ li òke Baṣani.
16 Eṣe ti ẹnyin nfi ilara wò, ẹnyin òke, òke na ti Ọlọrun fẹ lati ma gbe? nitõtọ, Oluwa yio ma gbe ibẹ lailai.
17 Ainiye ni kẹkẹ́ ogun Ọlọrun, ani ẹgbẹrun ati ẹgbẹgbẹrun: Oluwa mbẹ larin wọn, ni Sinai ni ibi mimọ́ nì.
18 Iwọ ti gòke si ibi giga, iwọ ti di igbekun ni igbekun lọ: iwọ ti gbà ẹ̀bun fun enia: nitõtọ, fun awọn ọlọtẹ̀ pẹlu, ki Oluwa Ọlọrun ki o le ma ba wọn gbe.
19 Olubukún li Oluwa lojojumọ, bi a dì ẹrù rù wa; Ọlọrun na ni igbala wa.
20 Ẹniti iṣe Ọlọrun wa li Ọlọrun igbala; ati lọwọ Jehofah Oluwa, li amúwa lọwọ ikú wà.
21 Nitori Ọlọrun yio fọ ori awọn ọta rẹ̀, ati agbari onirun ti iru ẹniti nrìn sibẹ ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
22 Oluwa wipe, emi o tun mu pada lati Baṣani wá, emi o tun mu wọn pada lati ibu okun wá.
23 Ki ẹsẹ rẹ ki o le pọ́n ninu ẹ̀jẹ awọn ọta rẹ, ati àhọn awọn aja rẹ ninu rẹ̀ na.
24 Nwọn ti ri ìrin rẹ, Ọlọrun; ani ìrin Ọlọrun mi, Ọba mi, ninu ibi mimọ́ nì.
25 Awọn akọrin lọ niwaju, awọn olohunelo orin kẹhin; larin awọn ọmọbirin ti nwọn nlu ìlu.
26 Ẹ fi ibukún fun Ọlọrun li ẹgbẹgbẹ, ani fun Oluwa, ẹnyin ti o ti orisun Israeli wá.
27 Nibẹ ni Benjamini kekere wà, pẹlu olori wọn, awọn ọmọ-alade Juda pẹlu awọn igbimọ wọn, awọn ọmọ-alade Sebuloni, ati awọn ọmo-alade Naftali.
28 Ọlọrun rẹ ti paṣẹ agbara rẹ: Ọlọrun fi ẹsẹ eyi ti o ti ṣe fun wa mulẹ.
29 Nitori tempili rẹ ni Jerusalemu li awọn ọba yio ma mu ọrẹ fun ọ wá.
30 Ba awọn ẹranko ẽsu wi, ọ̀pọlọpọ awọn akọ-malu, pẹlu awọn ọmọ-malu enia, titi olukulùku yio fi foribalẹ pẹlu ìwọn fadaka: tú awọn enia ti nṣe inu didùn si ogun ka.
31 Awọn ọmọ-alade yio ti Egipti jade wá; nisisiyi ni Etiopia yio nà ọwọ rẹ̀ si Ọlọrun.
32 Ẹ kọrin si Ọlọrun, ẹnyin ijọba aiye; ẹ kọrin iyìn si Oluwa.
33 Si ẹniti ngùn ati ọrun de ọrun atijọ; wò o, o fọhùn rẹ̀, eyi na li ohùn nla.
34 Ẹ jẹwọ agbara fun Ọlọrun; ọlánla rẹ̀ wà lori Israeli, ati agbara rẹ̀ mbẹ li awọsanma.
35 Ọlọrun, iwọ li ẹ̀ru lati ibi mimọ́ rẹ wọnni wá: Ọlọrun Israeli li On, ti nfi ilera ati agbara fun awọn enia rẹ̀. Olubukún li Ọlọrun!

## ORIN 69.

ỌLỌRUN, gbà mi; nitoriti omi wọnni wọ̀ inu lọ si ọkàn mi.
2 Emi rì ninu irà jijin, nibiti ibuduro kò si, emi de inu omi jijin wọnni, nibiti iṣan-omi ṣàn bò mi lori.
3 Agara ẹkun mi da mi: ọfun mi gbẹ: oju kún mi nigbati emi duro de Ọlọrun mi.
4 Awọn ti o korira mi lainidi jù irun ori mi lọ: awọn ti nṣe ọta mi laiṣẹ, ti iba pa mi run, nwọn lagbara: nigbana ni mo san ohun ti emi kò mu.
5 Ọlọrun, iwọ mọ̀ wère mi, ẹ̀ṣẹ mi kò si lumọ kuro loju rẹ.
6 Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, máṣe je ki oju ki o tì awọn ti o duro de ọ nitori mi: máṣe jẹ ki awọn ti nwá ọ ki o damu nitori mi, Ọlọrun Israeli.
7 Nitoripe nitori tirẹ li emi ṣe nrù ẹ̀gan; itiju ti bo mi loju.
8 Emi di àjeji si awọn arakọnrin mi, ati alejo si awọn ọmọ iya mi.
9 Nitori ti itara ile rẹ ti jẹ mi tan; ati ẹ̀gan awọn ti o gàn ọ, ṣubu lù mi.
10 Nigbati mo sọkun, ti mo si nfi àwẹ jẹ ara mi ni ìya, eyi na si di ẹ̀gan mi.
11 Emi fi aṣọ ọ̀fọ ṣe aṣọ mi pẹlu: mo si di ẹni-owe fun wọn.
12 Awọn ti o joko li ẹnu-bode nsọ̀rọ si mi; emi si di orin awọn ọmuti.
13 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, iwọ li emi ngbadura mi si, Oluwa, ni igba itẹwọgba: Ọlọrun, ninu ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ da mi lohùn, ninu otitọ igbala rẹ.
14 Yọ mi kuro ninu ẹrẹ̀, má si ṣe jẹ ki emi ki o rì: gbigbà ni ki a gbà mi lọwọ awọn ti o korira mi, ati ninu omi jijin wọnni.
15 Máṣe jẹ ki kikún-omi ki o bò mi mọlẹ, bẹ̃ni ki o máṣe jẹ ki ọgbun ki o gbé mi mì,

Digitized by Google

ki o má si ṣe jẹ ki iho ki o pa ẹnu rẹ̀ de mọ́
mi.
16 Oluwa, da mi lohùn ; nitori ti iṣeun
ifẹ rẹ dara, yipada si mi gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ
irọnu ãnu rẹ.
17 Ki o má si ṣe pa oju rẹ mọ́ kuro lara
iranṣẹ rẹ: emi sa wà ninu ipọnju ; yara,
da mi lohùn.
18 Sunmọ ọkàn mi, si rà a pada: gbà
mi nitori awọn ọta mi.
19 Iwọ ti mọ̀ ẹ̀gan mi ati ìtiju mi, ati
alailọla mi: gbogbo awọn ọta mi li o wà
niwaju rẹ.
20 Ẹgan ti bà mi ni inu jẹ ; emi si kún
fun ikãnu : emi si woye fun ẹniti yio ṣãnu
fun mi, ṣugbọn kò si ; ati fun awọn olutu-
nu, emi kò si ri ẹnikan.
21 Nwọn fi orõro fun mi pẹlu li ohun
jijẹ mi ; ati li ongbẹ mi nwọn fun mi li ọti
kikan ni mimu.
22 Jẹ ki tabili wọn ki o di ikẹkun niwa-
ju wọn : fun awọn ti o wà li alafia, ki o si
di okùn didẹ.
23 Jẹ ki oju wọn ki o ṣú, ki nwọn ki o
má riran, ki o si ma mu ẹgbẹ́ wọn gbọn
nigbagbogbo.
24 Dà irunu rẹ si wọn lori, si jẹ ki ikan-
nu ibinu rẹ ki o le wọn ba.
25 Jẹ ki ibujoko wọn ki o di ahoro ; ki
ẹnikẹni ki o máṣe gbe inu agọ wọn.
26 Nitori ti nwọn nṣe inunibini si ẹniti
iwọ ti lù ; nwọn si nsọ̀rọ ibinujẹ ti awọn ti
iwọ ti ṣá li ọgbẹ.
27 Fi ẹ̀ṣẹ kún ẹ̀ṣẹ wọn : ki o má si ṣe jẹ
ki nwọn ki o wá sinu ododo rẹ.
28 Nù wọn kuro ninu iwe awọn alãye,
ki a má si kọwe wọn pẹlu awọn olododo.
29 Ṣugbọn talaka ati ẹni-ikãnu li emi,
Ọlọrun jẹ ki igbala rẹ ki o gbé mi leke.
30 Emi o fi orin yìn orukọ Ọlọrun, emi
o si fi ọpẹ gbé orukọ rẹ̀ ga.
31 Eyi pẹlu ni yio wù Oluwa jù ọda-malu
tabi akọ-malu lọ ti o ni iwo ati bàta ẹsẹ.
32 Awọn onirẹlẹ yio ri eyi, inu wọn o si
dùn: ọkàn ẹnyin ti nwá Ọlọrun yio si wà
lãye.
33 Nitoriti Oluwa gbohùn awọn talaka,
kò si fi oju pa awọn ara tubu rẹ̀ rẹ́.
34 Jẹ ki ọrun on aiye ki o yìn i, okun
ati ohun gbogbo ti nrakò ninu wọn.
35 Nitoriti Ọlọrun yio gbà Sioni là, yio
si kọ́ ilu Juda wọnni: ki nwọn ki o le ma
gbe ibẹ, ki nwọn ki o le ma ni i ni ilẹ-ini.
36 Iru-ọmọ awọn iranṣẹ rẹ̀ pẹlu ni yio
ma jogun rẹ̀ : awọn ti o si fẹ orukọ rẹ̀ ni
yio ma gbe inu rẹ̀.

## ORIN 70.

ỌLỌRUN, yara gbà mi ; Oluwa, yara lati
ràn mi lọwọ.
2 Ki oju ki o tì awọn ti nwá ọkàn mi,
ki nwọn ki o si dãmu: ki nwọn ki o si
pada sẹhin, ki a si dãmu awọn ti nwá ifa-
rapa mi.
3 Ki a pa wọn li ẹhin dà fun ère itiju
awọn ti nwi pe, A ! a !
4 Ki gbogbo awọn ti nwá ọ ki o ma yọ̀,
ki inu wọn ki o si ma dùn nipa tirẹ : ki
iru awọn ti o si fẹ igbala rẹ ki o ma wi ni-
gbagbogbo pe, Ki a gbé Ọlọrun ga !
5 Ṣugbọn talaka ati alaini li emi: Ọlọ-
run, yara si mi : iwọ li oluranlọwọ ati olu-
gbala mi : Oluwa, máṣe pẹ titi.

## ORIN 71.

OLUWA, iwọ ni mo gbẹkẹ mi le: lai
máṣe jẹ ki a dãmu mi.
2 Gbà mi nipa ododo rẹ, ki o si mu mi
yọ̀: dẹ eti rẹ si mi, ki o si gbà mi.
3 Iwọ ni ki o ṣe ibujoko apata mi, nibi-
ti emi o gbe ma rè nigbagbogbo: iwọ ti
paṣẹ lati gbà mi ; nitori iwọ li apata ati
odi agbara mi,
4 Gbà mi, Ọlọrun mi, li ọwọ awọn enia
buburu, li ọwọ alaiṣododo ati ìka ọkọnrin.
5 Nitori iwọ ni ireti mi, Oluwa Ọlọrun ;
iwọ ni igbẹkẹle mi lati igba ewe mi.
6 Ọwọ rẹ li a ti fi gbé mi duro lati inu
wá : iwọ li ẹniti o mu mi jade lati inu iya
mi wá: nipasẹ rẹ ni iyìn mi wà nigbagbo-
gbo.
7 Emi dabi ẹni-iyanu fun ọ̀pọlọpọ enia,
ṣugbọn iwọ li àbo mi ti o lagbara.
8 Jẹ ki ẹnu mi ki o kún fun iyìn rẹ ati
fun ọlá rẹ li ọjọ gbogbo.
9 Máṣe ṣa mi tì ni ìgba ogbó ; máṣe kọ̀
mi silẹ nigbati agbara mi ba yẹ̀.
10 Nitori awọn ọta mi nsọ̀rọ si mi ;
awọn ti nṣọ ọkàn mi si gbimọ̀ pọ̀.
11 Nwọn wipe, Ọlọrun ti kọ̀ ọ silẹ: ẹ
lepa ki ẹ si mu u ; nitori ti kò si ẹniti yio
gbà a.
12 Ọlọrun, máṣe jina si mi: Ọlọrun mi,
yara si iranlọwọ mi.
13 Jẹ ki nwọn ki o dãmu, ki a si run
awọn ti nṣe ọta ọkàn mi, ki a si fi ẹ̀gan ati
àbukun bo awọn ti nwá ifarapa mi.
14 Ṣugbọn emi o ma reti nigbagbogbo,
emi o si ma fi iyìn kún iyìn rẹ.
15 Ẹnu mi yio ma fi ododo rẹ ati igbala
rẹ hàn li ọjọ gbogbo ; emi kò sa mọ̀ iye rẹ̀.
16 Emi o wá li agbara Oluwa Ọlọrun:

Digitized by Google

emi o ma da ọ̀rọ ododo rẹ sọ, ani tirẹ nikan.

17 Ọlọrun, iwọ ti kọ́ mi lati igba ewe mi wá: ati di isisiyi li emi ti nsọ̀rọ iṣẹ iyanu rẹ.

18 Pẹlupẹlu, nigbati emi di arugbo tan ti mo hewu, Ọlọrun máṣe kọ̀ mi; titi emi o fi fi ipá rẹ hàn fun iran yi, ati agbara rẹ fun gbogbo awọn ara ẹ̀hin.

19 Ọlọrun ododo rẹ ga jọjọ pẹlu, ẹniti o ti nṣe nkan nla: Ọlọrun, tali o dabi iwọ!

20 Iwọ ti o fi iṣẹ nla ati kikan hàn mi, ni yio si tun mi ji, yio si tun mu mi sọ si ọ̀ke lati ọgbun ilẹ wá.

21 Iwọ o sọ ọlá mi di pupọ̀, iwọ o si tù mi ninu niha gbogbo.

22 Emi o si fi ohun-elo orin yìn ọ pẹlu, ani otitọ rẹ, Ọlọrun mi: iwọ li emi o ma fi duru kọrin si, iwọ Ẹni-Mimọ́ Israeli.

23 Ete mi yio yọ̀ gidigidi, nigbati mo ba nkọrin si ọ: ati ọkàn mi, ti iwọ ti rapada.

24 Ahọn mi pẹlu yio si ma sọ̀rọ ododo rẹ titi li ọjọ gbogbo: nitoriti nwọn dãmu, a si doju tì awọn ti nwá ifarapa mi.

## ORIN 72.

ỌLỌRUN, fi idajọ rẹ fun ọba, ati ododo rẹ fun ọmọ ọba.

2 On o ma fi ododo ṣe idajọ awọn enia rẹ, yio si ma fi ẹtọ́ ṣe idajọ awọn talaka rẹ.

3 Awọn ọ̀ke nla yio ma mu alafia fun awọn enia wá, ati awọn ọ̀ke kekeke nipa ododo.

4 On o ma ṣe idajọ awọn talaka enia, yio ma gbà awọn ọmọ awọn alaini, yio si fà aninilara ya pẹrẹ-pẹrẹ.

5 Nwọn o si ma bẹ̀ru rẹ, niwọ̀n bi õrùn ati oṣupa yio ti pẹ to, lati irandiran.

6 On o rọ̀ si ilẹ bi ọ̀jo si ori koriko irẹ́-mọlẹ: bi ọwọ ọ̀jo ti o rin ilẹ.

7 Li ọjọ rẹ̀ li awọ̀n olododo yio gbilẹ ati ọ̀pọlọpọ alafia niwọn bi ọ̀ṣupa yio ti pẹ to.

8 On o si jọba lati okun de okun, ati lati odò nì de opin aiye.

9 Awọn ti o joko li aginju yio tẹriba fun u; awọn ọta rẹ̀ yio si lá erupẹ ilẹ.

10 Awọn ọba Tarṣiṣi, ati ti awọn erekuṣu yio mu ọrẹ wá: awọn ọba Ṣeba ati ti Seba yio mu ẹ̀bun wá.

11 Nitõtọ, gbogbo awọn ọba ni yio wolẹ niwaju rẹ̀: gbogbo awọn orilẹ-ède ni yio ma sìn i.

12 Nitori yio gbà alaini nigbati o ba nke: talaka pẹlu, ati ẹniti kò li oluranlọwọ.

13 On o da talaka ati alaini si, yio si gbà ọkàn awọn alaini là.

14 On o rà ọkàn wọn pada lọwọ ẹ̀tan ati ìwa-agbara: iyebiye si li ẹ̀jẹ wọn li oju rẹ̀.

15 On o si yè, on li a o si fi wura Ṣeba fun: a o si ma gbadura fun u nigbagbogbo: lojojumọ li a o si ma yìn i.

16 Ikúnwọ ọkà ni yio ma wà lori ilẹ, lori awọn òke nla li eso rẹ̀ yio ma mì bi Lebanoni: ati awọn ti inu ilu yio si ma gbà bi koriko ilẹ.

17 Orukọ rẹ̀ yio wà titi lai: orukọ rẹ̀ yio ma gbilẹ niwọn bi õrun yio ti pẹ to: nwọn o si ma bukún u fun ara wọn nipasẹ rẹ̀: gbogbo awọn orilẹ-ède ni yio ma pè e li alabukúnfun.

18 Olubukún li Oluwa Ọlọrun, Ọlọrun Israeli, ẹnikanṣoṣo ti nṣe ohun iyanu.

19 Olubukún li orukọ rẹ̀ ti o li ogo titi lai: ki gbogbo aiye ki o si kún fun ogo rẹ̀; Amin Amin.

*Adura Dafidi ọmọ Jesse pari.*

---

# IWE III.

## ORIN 73.

NITÕTỌ Ọlọrun ṣeun fun Israeli, fun iru awọn ti iṣe alaiya mimọ́.

2 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, ẹsẹ mi fẹrẹ yẹ̀ tan; ìrin mi fẹrẹ yọ́ tan.

3 Nitori ti emi ṣe ilara si awọn aṣefefe, nigbati mo ri alafia awọn enia buburu.

4 Nitoriti kò si irora ninu ikú wọn: agbara wọn si pọ̀.

5 Nwọn kò ni ipin ninu iyọnu enia; bẹ̃ni a kò si wahala wọn pẹlu ẹlomiran.

6 Nitorina ni igberaga ṣe ká wọn lọrun bi ẹ̀wọn ọṣọ́; ìwa-ipa bò wọn mọle bi aṣọ.

7 Oju wọn yọ jade fun isanra: nwọn ní jù bi ọkàn wọn ti nfẹ lọ.

8 Nwọn nṣẹsin, nwọn si nsọ̀rọ buburu niti inilara: nwọn nsọ̀rọ lati ibi giga.

9 Nwọn gbé ẹnu wọn le ọrun, ahọn wọn si nrìn ilẹ já.

10 Nitorina li awọn enia rẹ̀ ṣe yipada si ihin: ọ̀pọlọpọ omi li a si npọn jade fun wọn.

11 Nwọn si wipe, Ọlọrun ti ṣe mọ̀? ìmọ ha wà ninu Ọga-ogo?

12 Kiyesi i, awọn wọnyi li alaìwa-bi-ọlọrun, ẹniti aiye nsan, nwọn npọ̀ li ọrọ̀.

13 Nitõtọ li asan ni mo wẹ̀ aiya mi mọ́, ti mo si wẹ̀ ọwọ mi li ailẹ̀ṣẹ.

Digitized by Google

14 Nitoripe ni gbogbo ọjọ li a nyọ mi
lẹnu, a si nnà mi li orowurọ.
15 Bi emi ba pe, emi o fọ̀ bayi: kiyesi
i, emi o ṣẹ̀ si iran awọn ọmọ rẹ̀.
16 Nigbati mo rò lati mọ̀ eyi, o ṣoro li
oju mi.
17 Titi mo fi lọ sinu ibi-mimọ́ Ọlọrun;
nigbana ni mo mọ̀ igbẹhin wọn.
18 Nitõtọ iwọ gbé wọn ka ibi yiyọ́: iwọ
tì wọn ṣubu sinu iparun.
19 Bawo li a ti mu wọn lọ sinu idahoro
yi, bi ẹnipe ni iṣẹju kan! ibẹru li a fi nrun
wọn patapata.
20 Bi igbati ẹnikan ba ji li oju alá;
bẹ̃ni Oluwa, nigbati iwọ ba ji, iwọ o ṣe
àbukun àworan wọn.
21 Bayi ni inu mi bajẹ, ẹgún si gun mi
li ọkàn mi.
22 Bẹ̃ni mo ṣiwere, ti emi kò si mọ̀
nkan; mo dabi ẹranko niwaju rẹ.
23 Ṣugbọn emi wà pẹlu rẹ nigbagbogbo:
iwọ li o ti di ọwọ ọtún mi mu.
24 Iwọ o fi ìmọ rẹ tọ́ mi li ọ̀na, ati ni-
gbẹhin iwọ o gbà mi sinu ogo.
25 Tani mo ni li ọrun bikoṣe iwọ? kò si
si ohun ti mo fẹ li aiye pẹlu rẹ.
26 Ẹran-ara mi ati aiya mi di ãrẹ̀ tan:
ṣugbọn Ọlọrun ni apata aiya mi, ati ipin
mi lailai.
27 Sa wò o, awọn ti o jina si ọ yio ṣegbe:
iwọ ti pa gbogbo wọn run ti nṣe àgbere
kirikiri kuro lọdọ rẹ.
28 Ṣugbọn o dara fun mi lati sunmọ
Ọlọrun: emi ti gbẹkẹ mi le Oluwa Ọlọrun,
ki emi ki o le ma sọ̀rọ iṣẹ rẹ gbogbo.

## ORIN 74.

ỌLỌRUN, ẽṣe ti iwọ fi ta wa nù titi lai!
ẽṣe ti ibinu rẹ fi nrú si agutan papa
rẹ?
2 Ranti ijọ enia rẹ ti iwọ ti rà nigba ati-
jọ; ilẹ-ini rẹ ti iwọ ti rà pada; òke Sioni
yi, ninu eyi ti iwọ ngbe.
3 Gbé ẹsẹ rẹ soke si ahoro lailai nì; ani
si gbogbo eyiti ọta ti fi buburu ṣe ni ibi-
mimọ́.
4 Awọn ọta rẹ nke ramu-ramu lãrin ijọ
enia rẹ; nwọn gbé asia wọn soke fun àmi.
5 Nwọn dabi ọkọnrin ti ngbé akeke rẹ̀
soke ninu igbo didi,
6 Ṣugbọn nisisiyi iṣẹ ọnà finfin ni nwọn
fi akeke ati òlu wó lulẹ pọ̀ li ẹrinkan.
7 Nwọn tinabọ ibi-mimọ́ rẹ, ni wiwo
ibujoko orukọ rẹ lulẹ, nwọn sọ ọ di ẽri.
8 Nwọn wi li ọkàn wọn pe, Ẹ jẹ ki a
run wọn pọ̀: nwọn ti kun gbogbo ile Ọlọ-
run ni ilẹ na.
9 Awa kò ri àmi wa: kò si woli kan
mọ́: bẹ̃ni kò si ẹnikan ninu wa ti o mọ̀ bi
yio ti pẹ to.
10 Ọlọrun, ọta yio ti kẹgan pẹ to? ki
ọta ki o ha ma sọ̀rọ òdi si orukọ rẹ lailai?
11 Ẽṣe ti iwọ fi fa ọwọ rẹ sẹhin, ani ọwọ
ọtún rẹ? fà a yọ jade kuro li owokan aiya
rẹ, ki o si pa a run.
12 Nitori Ọlọrun li Ọba mi li atijọ wá,
ti nṣiṣe igbala lãrin aiye.
13 Iwọ li o ti yà okun ni meji nipa
agbara rẹ: iwọ ti fọ́ ori awọn erinmi ninu
omi.
14 Iwọ fọ́ ori Lefiatani tũtu, o si fi i ṣe
onjẹ fun awọn ti ngbe inu ijù.
15 Iwọ là orisun ati iṣan-omi: iwọ gbẹ
awọn odò nla.
16 Tirẹ li ọsán, tirẹ li oru pẹlu: iwọ li
o ti pèse imọlẹ ati õrùn.
17 Iwọ li o ti pàla eti aiye: iwọ li o ṣe
igba ẹrun ati igba otutu.
18 Ranti eyi, Oluwa, pe ọta nkẹgàn, ati
pe awọn enia buburu nsọ̀rọ odi si orukọ rẹ.
19 Máṣe fi ọkàn àdaba rẹ le ẹranko igbẹ
lọwọ: máṣe gbagbe ijọ awọn talaka rẹ
lailai.
20 Juba majẹmu nì: nitori ibi òkunkun
aiye wọnni o kún fun ibugbe ìka.
21 Máṣe jẹ ki ẹniti a ni lara ki o pada ni
ìtiju; jẹ ki talaka ati alaini ki o yìn orukọ
rẹ.
22 Ọlọrun, dide, gbà ẹjọ ara rẹ rò: ranti
bi aṣiwere enia ti ngàn ọ lojojumọ.
23 Máṣe gbagbe ohùn awọn ọta rẹ: irọ-
kẹkẹ awọn ti o dide si ọ npọ̀ si i nigbagbo-
gbo.

## ORIN 75.

ỌLỌRUN, iwọ li awa fi ọpẹ fun, iwọ li
awa fi ọpẹ fun nitori orukọ rẹ sunmọ
itosi, iṣẹ iyanu rẹ fi hàn.
2 Nigbati akokò mi ba de, emi o fi otitọ
ṣe idajọ.
3 Aiye ati gbogbo awọn ti ngbe inu rẹ̀
warìri: emi li o rù ọwọ̀n rẹ̀.
4 Emi wi fun awọn agberaga pe, Ẹ máṣe
gbéraga mọ́: ati fun awọn enia buburu pe,
Ẹ máṣe gbé iwo nì soke.
5 Ẹ máṣe gbé iwo nyin ga: ẹ máṣe fi
ọrùn lile sọ̀rọ.
6 Nitori ti igbeleke kò ti ìla-õrùn wá,
tabi ni ìwọ-õrùn, bẹ̃ni kì iṣe lati gusu wá.
7 Ṣugbọn Ọlọrun li onidajọ: o sọ ọkan
kalẹ, o gbé ẹlomiran leke.

Digitized by Google

8 Nitoripe li ọwọ Oluwa li ago kan wà,
ọti-waini na si pọ́n: o kún fun àdalu: o
si dà jade ninu rẹ̀; ṣugbọn gẹ̀dẹgẹdẹ rẹ̀,
gbogbo awọn enia buburu aiye ni yio fun
u li afun-mu.
9 Ṣugbọn emi o ma sọ titi lai, emi o ma
kọrin iyìn si Ọlọrun Jakobu.
10 Gbogbo iwo awon enia buburu li emi
o ke kuro; ṣugbọn iwo awọn olododo li
emi o gbé soke.

## ORIN 76.

NI Juda li a gbe mọ̀ Ọlọrun: orukọ rẹ̀ si
pọ̀ ni Israeli.
2 Ni Salemu pẹlu li agọ rẹ̀ wà, ati ibu-
joko rẹ̀ ni Sioni.
3 Nibẹ li o gbe ṣẹ́ ọfà ọrun, apata, ati
idà, ati ogun na.
4 Iwọ li ogo ati ọlá jù òke-nla ikogun
wọnni lọ.
5 A kó awọn alaiya lile ni ikogun, nwọn
ti sùn orun wọn, gbogbo ọkọnrin alagbara
kò si ri ọwọ wọn.
6 Nipa ibawi re, Ọlọrun Jakobu, ati
kẹkẹ́-ogun ati ẹṣin sun orun asunkú.
7 Iwọ, ani iwọ li o̩ ni ìbẹru: ati tani
yio le duro niwaju rẹ, nigbati iwọ ba binu
lẹ̃kan ?
8 Iwọ mu idajọ di gbigbọ́ lati ọrun wá:
ilẹ aiye bẹ̀ru o si duro jẹ.
9 Nigbati Ọlọrun dide si idajọ, lati gbà
gbogbo ọlọkan-tutu aiye là.
10 Nitõtọ ibinu enia yio yìn ọ: nigbati
iwọ ba fi ibinu iyokù di ara rẹ li amure.
11 Ẹ ṣe ileri ifẹ, ki ẹ si san a fun Oluwa,
Ọlọrun nyin: jẹ ki gbogbo awọn ti o yi i
ka ki o mu ẹ̀bun wá fun ẹniti a ba ma bẹ̀ru.
12 On o ke ẹmi awọn ọmọ alade kuro:
on si di ẹ̀ru si awọn ọba aiye.

## ORIN 77.

EMI fi ohùn mi kigbe si Ọlọrun, ani si
Ọlọrun ni mo fi ohùn mi kepè; o si fi
eti si mi.
2 Li ọjọ ipọnju mi emi ṣe afẹri Ọlọrun:
ọwọ mi nnà li oru, kò si rẹ̀ silẹ: ọkàn mi
kọ̀ ati tù ninu.
3 Emi ranti Ọlọrun, emi kẹdun: emi ṣe
aroye, ẹmi mi si rẹ̀wẹsi.
4 Iwọ kò fẹ ki emi ki o fi oju ba orun:
ẹnu yọ mi tobẹ̃ ti emi kò le sọ̀rọ:
5 Emi ti nrò ọjọ atijọ, ọdun igbani,
6 Mo ranti orin mi li oru: emi mba aiya
mi sọ̀rọ: ọkàn mi si nṣe awari jọjọ.
7 Oluwa yio ha ṣa ni tì lailai? kì o si ṣe
oju rere mọ́?
8 Ãnu rẹ̀ ha lọ lailai? ileri rẹ̀ ha yẹ̀ titi
lai?
9 Ọlọrun ha gbagbe lati ṣe oju rere?
ninu ibinu rẹ̀ o ha sé irọnu ãnu rẹ̀ mọ́?
10 Emi wipe, Eyi li ailera mi! eyi li
ọdun ọwọ ọtún Ọga-ogo!
11 Emi o ranti iṣẹ Oluwa: nitõtọ emi o
ranti iṣẹ iyanu rẹ atijọ.
12 Ṣugbọn emi o ma ṣe àṣaro gbogbo iṣẹ
rẹ pẹlu, emi o si ma sọ̀rọ iṣẹ rẹ.
13 Ọlọrun, ọ̀na rẹ mbẹ ninu ìwa-mimọ́:
tali alagbara ti o tobi bi Ọlọrun?
14 Iwọ li Alagbara ti nṣe iṣẹ iyanu:
iwọ li o ti fi ipá rẹ hàn ninu awọn enia.
15 Iwọ li o ti fi apá rẹ rà awọn enia rẹ
pada, awọn ọmọ Jakobu ati Josefu.
16 Omi ri ọ, Ọlọrun, omi ri ọ, ẹ̀ru bà
wọn: nitõtọ ara ibú kò balẹ.
17 Awọsanma dà omi silẹ: ojusanma
rán iró jade: ọfà rẹ jade lọ pẹlu.
18 Ohùn ãrá rẹ nsan li ọrun: manama-
na nkọ si aiye, ilẹ nwa-rìri, o si mì.
19 Ọ̀na rẹ mbẹ li okun, ati ipa rẹ ninu
awọn omi nla, ipasẹ rẹ li a kò si mọ̀.
20 Iwọ dà awọn enia rẹ bi ọ̀wọ-ẹran nipa
ọwọ Mose ati Aaroni.

## ORIN 78.

FI eti silẹ, ẹnyin enia mi, si ofin mi: dẹ
eti nyin silẹ si ọ̀rọ ẹnu mi.
2 Emi o ya ẹnu mi li owe: emi o sọ ọ̀rọ
atijọ ti o ṣokunkun jade.
3 Ti awa ti gbọ́, ti a si ti mọ̀, ti awọn
baba wa si ti sọ fun wa.
4 Awa kì yio pa wọn mọ́ kuro lọdọ
awọn ọmọ wọn, ni fifi iyìn Oluwa, ati ipa
rẹ̀, ati iṣẹ iyanu ti o ti ṣe hàn fun iran ti
mbọ.
5 Nitori ti o gbé ẹri kalẹ ni Jakobu, o
si sọ ofin kan ni Israeli, ti o ti pa li aṣẹ fun
awọn baba wa pe, ki nwọn ki o le sọ wọn
di mimọ̀ fun awọn ọmọ wọn.
6 Ki awọn iran ti mbọ̀ ki o le mọ̀, ani
awọn ọmọ ti a o bi: ti yio si dide, ti yio
si sọ fun awọn ọmọ wọn:
7 Ki nwọn ki o le ma gbé ireti wọn le
Ọlọrun, ki nwọn ki o má si ṣe gbagbe iṣẹ
Ọlọrun, ṣugbọn ki nwọn ki o pa ofin rẹ̀ mọ́.
8 Ki nwọn ki o máṣe dabi awọn baba
wọn, iran agidi ati ọlọ̀tẹ; iran ti kò fi
ọkàn wọn le otitọ, ati ẹmi ẹniti kò ba
Ọlọrun duro ṣinṣin.
9 Awọn ọmọ Efraimu ti o hamọra ogun,
ti nwọn mu ọrun, nwọn yipada li ọjọ ogun.
10 Nwọn kò pa majẹmu Ọlọrun mọ́,
nwọn si kọ̀ lati ma rìn ninu ofin rẹ̀.

Digitized by Google

11 Nwọn si gbagbe iṣẹ rẹ̀, ati ohun iya-
nu rẹ̀, ti o ti fi hàn fun wọn.
12 Ohun iyanu ti o ṣe niwaju awọn
baba wọn ni ilẹ Egipti, ani ni igbẹ So-
ani.
13 O pin okun ni ìya, o si mu wọn là a
ja; o si mu omi duro bi bèbe.
14 Li ọsan pẹlu o fi awọsanma ṣe amọna
wọn, ati li oru gbogbo pẹlu imọlẹ iná.
15 O sán apata li aginju, o si fun wọn li
omi mimu lọpọlọpọ, bi ẹnipe lati inu ibú
wá.
16 O si mu iṣàn-omi jade wá lati inu
apata, o si mu omi ṣàn silẹ bi odò nla.
17 Nwọn si tún ṣẹ̀ si i; ni ṣiṣọtẹ si Ọga-
ogo li aginju.
18 Nwọn si dán Ọlọrun wò li ọkàn wọn,
ni bibère onjẹ fun ifẹkufẹ wọn.
19 Nwọn si sọ̀rọ si Ọlọrun; nwọn wipe,
Ọlọrun ha le tẹ́ tabili li aginju?
20 Wò o! o lù apata, omi si tú jade,
iṣàn-omi si kún pupọ; o ha le funni li
àkara pẹlu? o ha le pèse ẹran fun awọn
enia rẹ̀?
21 Nitorina, Oluwa gbọ́ eyi, o binu:
bẽni iná ràn ni Jakobu, ibinu si ru ni
Israeli;
22 Nitori ti nwọn kò gbà Ọlọrun gbọ́,
nwọn kò si gbẹkẹle igbala rẹ̀.
23 O paṣẹ fun awọsanma lati òke wá, o
si ṣi ilẹkùn ọrun silẹ.
24 O si rọ̀jo Manna silẹ fun wọn ni jijẹ,
o si fun wọn li ọkà ọrun.
25 Enia jẹ onjẹ awọn angeli; o rán onjẹ
si wọn li ajẹyo.
26 O mu afẹfẹ ìla-õrun fẹ li ọrun, ati
nipa agbara rẹ̀ o mu afẹfẹ gusu wá.
27 O rọ̀jo ẹran si wọn pẹlu bi erupẹ ilẹ,
ati ẹiyẹ abiyẹ bi iyanrin okun.
28 O si jẹ ki o bọ́ si ãrin ibudo wọn, yi
agọ wọn ka.
29 Bẽni nwọn jẹ, nwọn si yo jọjọ: nito-
riti o fi ifẹ wọn fun wọn.
30 Nwọn kò kuro ninu ifẹkufẹ wọn;
nigbati onjẹ wọn si wà li ẹnu wọn.
31 Ibinu Ọlọrun de si ori wọn, o pa
awọn ti o sanra ninu wọn, o si lù awọn
ọdọmọkọnrin Israeli bolẹ.
32 Ninu gbogbo wọnyi nwọn nṣẹ̀ siwaju,
nwọn kò si gbà iṣẹ iyanu rẹ̀ gbọ́.
33 Nitorina li o ṣe run ọjọ wọn li asan,
ati ọdun wọn ni ijaiya.
34 Nigbati o pa wọn, nigbana ni nwọn
wá a kiri: nwọn si pada, nwọn bère Ọlọ-
run lakokò,
35 Nwọn si ranti pe, Ọlọrun li apata
wọn, ati Ọlọrun Ọga-ogo li Oludande wọn,
36 Ṣugbọn ẹnu wọn ni nwọn fi pọ́n ọ,
nwọn si fi ahọn wọn ṣeke si i.
37 Nitori ọkàn wọn kò ṣe dẽde pẹlu
rẹ̀, bẽni nwọn kò si duro ṣinṣin ni majẹmu
rẹ̀.
38 Ṣugbọn on, o kún fun iyọ́nu, o fi ẹ̀ṣẹ
wọn jì wọn, kò si run wọn: nitõtọ, nigba
pupọ̀ li o yi ibinu rẹ̀ pada, ti kò si ru gbo-
gbo ibinu rẹ̀ soke.
39 Nitoriti o ranti pe, enia ṣa ni nwọn;
afẹfẹ ti nkọja lọ, ti kò si tun pada wá
mọ.
40 Igba melo-melo ni nwọn sọ̀tẹ si i li
aginju, ti nwọn si bà a ninu jẹ ninu aṣálẹ!
41 Nitõtọ, nwọn yipada, nwọn si dan
Ọlọrun wò, nwọn si ṣe aropin Ẹni-Mimọ́
Israeli.
42 Nwọn kò ranti ọwọ rẹ̀, tabi ọjọ nì ti
o gbà wọn lọwọ ọta.
43 Bi o ti ṣe iṣẹ-àmi rẹ̀ ni Egipti, ati iṣẹ
iyanu rẹ̀ ni igbẹ Soani.
44 Ti o si sọ odò wọn di ẹ̀jẹ; ati omi
ṣiṣan wọn, ti nwọn kò fi le mu u.
45 O rán eṣinṣin sinu wọn, ti o jẹ wọn;
ati ọpọlọ, ti o run wọn.
46 O fi eso ilẹ wọn fun kokoro pẹlu, ati
iṣẹ wọn fun ẽṣú.
47 O fi yinyin pa àjara wọn, o si fi yin-
yin nla pa igi sikamore wọn.
48 O fi ohun ọ̀sin wọn pẹlu fun yinyin,
ati agbo-ẹran wọn fun manamana.
49 O mu kikoro ibinu rẹ̀ wá si wọn lara,
irunu ati ikannu, ati ipọnju, nipa riran
angeli ibi sinu wọn.
50 O ṣina silẹ fun ibinu rẹ̀; kò da ọkàn
wọn si lọwọ ikú, ṣugbọn o fi ẹmi wọn fun
àjakalẹ-àrun.
51 O si kọlu gbogbo awọn akọbi ni
Egipti, olori agbara wọn ninu agọ Hamu:
52 Ṣugbọn o mu awọn enia tirẹ̀ lọ bi
agutan, o si ṣe itọju wọn ni iju bi agbo-
ẹran.
53 O si ṣe amọna wọn li alafia, bẽni
nwọn kò si bẹ̀ru: ṣugbọn okun bò awọn
ọta wọn mọlẹ.
54 O si mu wọn wá si eti ibi-mimọ́ rẹ̀,
ani si òke yi ti ọwọ ọtún rẹ̀ ti rà.
55 O tì awọn keferi jade pẹlu kuro ni-
waju wọn, o si fi tita okùn pinlẹ fun wọn
ni ilẹ-ini, o si mu awọn ẹya Israeli joko
ninu agọ wọn.
56 Ṣugbọn nwọn dan a wò, nwọn si ṣọ̀tẹ
si Ọlọrun Ọga-ogo, nwọn kò si pa ẹri rẹ̀
mọ́.
57 Ṣugbọn nwọn yipada, nwọn ṣe alaiṣo-

Digitized by Google

titọ bi awọn baba wọn: nwọn si pẹhinda
si apakan bi ọrun ẹ̀tan.
58 Nitori ti nwọn fi ibi giga wọn bi i
ninu, nwọn si fi ere finfin wọn mu u jowu.
59 Nigbati Ọlọrun gbọ́ eyi, o binu, o si
korira Israeli gidigidi.
60 Bẽli o kọ̀ agọ Ṣilo silẹ, agọ ti o pa
ninu awọn enia.
61 O si fi agbara rẹ̀ fun igbekun, ati ogo
rẹ̀ le ọwọ ọta nì.
62 O fi awọn enia rẹ̀ fun idà pẹlu; o si
binu si ilẹ-ini rẹ̀.
63 Iná run awọn ọdọmọkọnrin wọn; a
kò si fi orin sin awọn wundia wọn ni iyawo.
64 Awọn alufa wọn ti oju idà ṣubu;
awọn opò wọn kò si pohunrere ẹkún.
65 Nigbana li Oluwa ji bi ẹnipe loju
orun, ati bi alagbara ti o nkọ nitori ọti-
waini.
66 O si kọlu awọn ọta rẹ̀ lẹhin; o sọ
wọn di ẹ̀gan titi aiye.
67 Pẹlupẹlu o kọ̀ agọ Josefu, kò si yàn
ẹ̀ya Efraimu:
68 Ṣugbọn o yan ẹ̀ya Juda, òke Sioni ti
o fẹ.
69 O si kọ́ ibi-mimọ́ rẹ̀ bi òke-ọrun, bi
ilẹ ti o ti fi idi rẹ̀ mulẹ lailai.
70 O si yàn Dafidi iranṣẹ rẹ̀, o si mu u
kuro lati inu agbo-agutan wá:
71 Lati má tọ̀ awọn agutan lẹhin, ti o
tobi fun oyun, o mu u lati ma bọ́ Jakobu,
enia rẹ̀, ati Israeli, ilẹ-ini rẹ̀.
72 Bẽli o bọ́ wọn gẹgẹ bi ìwa-titọ inu
rẹ̀; o si fi ọgbọ́n ọwọ rẹ̀ ṣe amọna wọn.

## ORIN 79.

ỌLỌRUN, awọn keferi wá si ilẹ-ini rẹ;
tempili mimọ́ rẹ ni nwọn sọ di ẽri;
nwọn sọ Jerusalemu di òkiti-alapa.
2 Okú awọn iranṣẹ rẹ ni nwọn fi fun
ẹiyẹ oju-ọrun li onjẹ, ẹran-ara awọn enia
mimọ́ rẹ fun ẹranko ilẹ.
3 Ẹ̀jẹ wọn ni nwọn ta silẹ bi omi yi
Jerusalemu ka; kò si si ẹniti yio gbé wọn
sìn.
4 Awa di ẹ̀gan si awọn aladugbo wa,
ẹlẹya ati iyọṣuti si awọn ti o yi wa ka.
5 Yio ti pẹ to, Oluwa? iwọ o binu titi
lailai? owú rẹ yio ha ma jó bi ina?
6 Dà ibinu rẹ si ori awọn keferi ti kò
mọ̀ ọ, ati si ori awọn ijọba ti kò kepe orukọ
rẹ.
7 Nitori ti nwọn ti mu Jakobu jẹ, nwọn
si sọ ibujoko rẹ̀ di ahoro.
8 Máṣe ranti ẹ̀ṣẹ awọn aṣaju wa si wa:
jẹ ki iyọnu rẹ ki o ṣaju wa nisisiyi: nitori
ti a rẹ̀ wa silẹ gidigidi.
9 Ràn wa lọwọ, Ọlọrun igbala wa, nitori
ogo orukọ rẹ: ki o si gbà wa, ki o si wẹ̀
ẹ̀ṣẹ wa nù, nitori orukọ rẹ.
10 Nitori kili awọn keferi yio ṣe wipe,
Nibo li Ọlọrun wọn wà? jẹ ki a mọ̀ igbẹsan
ẹ̀jẹ awọn iranṣẹ rẹ ti a ta silẹ loju wa ninu
awọn keferi.
11 Jẹ ki imi-ẹdun onde nì ki o wá siwaju
rẹ: gẹgẹ bi titobi agbara rẹ, iwọ dá awọn
ti a yàn si pipa silẹ:
12 Ki o si san ẹ̀gan wọn nigba meje fun
awọn aladugbo wa li aiya wọn, nipa eyiti
nwọn ngàn ọ, Oluwa.
13 Bẽli awa enia rẹ ati agutan papa rẹ,
yio ma fi ọpẹ fun ọ lailai, awa o ma fi iyìn
rẹ hàn lati irandiran.

## ORIN 80.

FI eti si ni, Oluṣọ-agutan Israeli, iwọ ti
o ndà Josefu bi ọwọ́-agutan; iwọ ti o
joko lãrin awọn kerubu tàn imọlẹ jade.
2 Niwaju Efraimu ati Benjamini ati
Manasse rú ipa rẹ soke ki o si wá fun
igbala wa.
3 Tún wa yipada, Ọlọrun, ki o si mu
oju rẹ tàn imọlẹ; a o si gbà wa là.
4 Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, iwọ o
ti binu pẹ to si adura awọn enia rẹ?
5 Iwọ fi onjẹ omije bọ́ wọn; iwọ si fun
wọn li omije mu li ọ̀pọlọpọ.
6 Iwọ sọ wa di ijà fun awọn aladugbo
wa: awọn ọta wa si nrẹrin ninu ara wọn.
7 Tún wa yipada, Ọlọrun awọn ọmọ-
ogun, ki o si mu oju rẹ tàn imọlẹ; a o si
gbà wa là.
8 Iwọ ti mu ajara kan jade ti Egipti
wá: iwọ ti tì awọn keferi jade, iwọ si
gbin i.
9 Iwọ ṣe àye silẹ fun u, iwọ si mu u ta
gbòngbo jinlẹ̀, o si kún ilẹ na.
10 A fi ojiji rẹ̀ bò awọn òke mọlẹ, ati
ẹka rẹ̀ dabi igi kedari Ọlọrun.
11 O yọ ẹka rẹ̀ sinu okun, ati ọwọ rẹ̀ si
odò nla nì.
12 Ẽṣe ti iwọ ha fi ya ọgbá rẹ̀ bẹ̃, ti
gbogbo awọn ẹniti nkọja lọ li ọ̀na nká a?
13 Imado lati inu igbo wá mba a jẹ, ati
ẹranko igbẹ njẹ ẹ run.
14 Yipada, awa mbẹ ọ, Ọlọrun awọn
ọmọ-ogun: wolẹ lati ọrun wá, ki o si wò ó,
ki o si bẹ àjara yi wò:
15 Ati agbala-àjara ti ọwọ ọtún rẹ ti
gbin, ati ọmọ ti iwọ ti mule fun ara rẹ.

Digitized by Google

16 O jona, a ke e lulẹ: nwọn ṣegbe nipa
ibawi oju rẹ.
17 Jẹ ki ọwọ rẹ ki o wà lara ọkọnrin
ọwọ ọtún rẹ nì, lara ọmọ-enia ti iwọ ti
mule fun ara rẹ.
18 Bẽli awa kì yio pada sẹhin kuro lọdọ
rẹ: mu wa yè, awa o si ma pè orukọ rẹ.
19 Tún wa yipada, Oluwa Ọlọrun awọn
ọmọ-ogun, mu oju rẹ tàn imọlẹ; a o si gbà
wa là.

## ORIN 81.

KỌRIN soke si Ọlọrun, ipa wa: ẹ ho iho
ayọ̀ si Ọlọrun Jakobu.
2 Ẹ mu orin mimọ́, ki ẹ si mu ìlu wá,
duru didùn pẹlu ohun-elo orin mimọ́.
3 Ẹ fun ipè li oṣù titún, ni ìgbà ti a lana
silẹ, li ọjọ ajọ wa ti o ni ironu.
4 Nitori eyi li aṣẹ fun Israeli, ati ofin
Ọlọrun Jakobu.
5 Eyi li o dasilẹ ni Josefu fun ẹri, nigbati
o là ilẹ Egipti ja; nibiti mo gbe gbọ́ ede ti
kò ye mi.
6 Mo gbé ejika rẹ̀ kuro ninu ẹrù: mo si
gbà agbọn li ọwọ rẹ̀.
7 Iwọ pè ninu ipọnju, emi si gbà ọ; emi
da ọ lohùn nibi ìkọkọ ãra: emi ridi rẹ nibi
omi ija.
8 Ẹ gbọ́, ẹnyin enia mi, emi o si jẹri si
ọ; Israeli, bi iwọ ba fetisi mi.
9 Kì yio si ọlọrun miran ninu nyin;
bẽni iwọ kì yio sìn ọlọrun àjeji.
10 Emi ni Oluwa Ọlọrun rẹ, ti o mu ọ
lati ilẹ Egipti jade wá: yà ẹnu rẹ gbòro,
emi o si kún u.
11 Ṣugbọn awọn enia mi kò fẹ igbọ́ ohùn
mi; Israeli kò si fẹ ti emi.
12 Bẽni mo fi wọn silẹ fun lile aiya wọn:
nwọn si nrìn ninu ero ara wọn.
13 Ibaṣepe awọn enia mi ti gbọ́ ti emi,
ati ki Israeli ki o ma rìn nipa ọ̀na mi!
14 Emi iba ti ṣẹ́ awọn ọta wọn lọgan,
emi iba si ti yi ọwọ mi pada si awọn ọta
wọn.
15 Awọn akorira Oluwa iba ti fi ori wọn
balẹ fun u; igba wọn iba si duro pẹ titi.
16 Alikama daradara ni on iba ma fi bọ́
wọn pẹlu: ati oyin inu apata ni emi iba si
ma fi tẹ́ ọ lọrun.

## ORIN 82.

ỌLỌRUN duro ninu ijọ awọn alagbara;
o nṣe idajọ ninu awọn ọlọrun.
2 Ẹnyin o ti ṣe idajọ aiṣõtọ pẹ to, ti ẹ o
si ma ṣe ojusaju awọn enia buburu?
3 Ṣe idajọ talaka, ati ti alaini-baba: ṣe
otitọ si awọn olupọnju ati alaini.
4 Gbà talaka ati alaini: yọ wọn li ọwọ
awọn enia buburu.
5 Nwọn kò mọ̀, bẽni nwọn kò fẹ ki oye
ki o ye wọn; nwọn nrìn li òkunkun; gbo-
gbo ipilẹ aiye yẹ̀ ni ipò wọn.
6 Emi ti wipe, ọlọrun li ẹnyin; awọn
ọmọ Ọga-ogo si ni gbogbo nyin.
7 Ṣugbọn ẹnyin o kú bi enia, ẹnyin o si
ṣubu bi ọkan ninu awọn ọmọ-alade.
8 Ọlọrun, dide, ṣe idajọ aiye: nitori iwọ
ni yio ni orilẹ-ède gbogbo.

## ORIN 83.

MÁṢE dakẹ, Ọlọrun: máṣe pa ẹnu rẹ mọ́,
ki o má si ṣe duro jẹ, Ọlọrun.
2 Sa wò o, awọn ọta rẹ nrọkẹ̀kẹ: awọn
ti o korira rẹ ti gbé ori soke.
3 Nwọn ti gbimọ̀ arekereke si awọn enia
rẹ, nwọn si ti gbìro si awọn ẹni-ìkọkọ rẹ.
4 Nwọn ti wipe, Ẹ wá, ẹ jẹ ki a ke wọn
kuro lati má wà li orilẹ-ède; ki orukọ
Israeli ki o máṣe si ni iranti mọ́.
5 Nitoriti nwọn ti gbimọ̀ pọ̀ ṣọkan:
nwọn ti dimọlu si ọ.
6 Agọ Edomu, ati ti awọn ọmọ Iṣmaeli;
ti Moabu, ati awọn ọmọ Hagari.
7 Gebali, ati Ammoni, ati Amaleki:
awọn ara Filistia pẹlu awọn ara Tire;
8 Assuri pẹlu dapọ̀ mọ wọn: nwọn ràn
awọn ọmọ Lotu lọwọ.
9 Ṣe wọn bi o ti ṣe awọn ara Midiani;
bi Sisera, bi Jabini, li odò Kiṣoni.
10 Ẹniti o ṣegbe ni Endori: nwọn di
àtan fun ilẹ.
11 Ṣe awọn ọlọla wọn bi Orebu ati bi
Sebu: ani, gbogbo awọn ọmọ-alade wọn bi
Seba ati Salmuna.
12 Awọn ti o wipe, Ẹ jẹ ki a gbà ibugbe
Ọlọrun wọnni fun ara wa ni ini.
13 Ọlọrun mi, ṣe wọn bi ãjà; bi akeku
koriko niwaju afẹfẹ.
14 Bi iná ti ijo igbo, ati bi ọwọ́ iná ti
imu òke-nla gbiná;
15 Bẽni ki o fi ẹ̀fufu rẹ ṣe inunibini si
wọn, ki o si fi ìji rẹ dẹrubà wọn.
16 Fi ìtiju kún wọn li oju: ki nwọn o
le ma ṣe afẹri orukọ rẹ, Oluwa.
17 Ki nwọn ki o dãmu, ki a si pọ́n wọn
loju lailai: nitõtọ, ki a dojutì wọn, ki
nwọn ki o ṣegbé.
18 Ki awọn enia ki o le mọ̀ pe iwọ,
orukọ ẹni-kanṣoṣo ti ijẹ Jehofah, iwọ li
Ọga-ogo lori aiye gbogbo.

Digitized by Google

## ORIN 84.

AGỌ rẹ wọnni ti li ẹwà to, Oluwa awọn ọmọ-ogun !

2 Ọkàn mi nfà nitõtọ, o tilẹ pe ongbẹ fun agbala Oluwa: aiya mi ati ara mi nkigbe si Ọlọrun alãye.

3 Nitõtọ, ologoṣẹ ri ile, ati alapandẹdẹ tẹ́ itẹ fun ara rẹ̀, nibiti yio gbe ma pa awọn ọmọ rẹ̀ mọ́ si, ani ni pẹpẹ rẹ wọnni, Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọba mi ati Ọlọrun mi.

4 Ibukún ni fun awọn ti ngbe inu ile rẹ: nwọn o ma yìn ọ sibẹ.

5 Ibukún ni fun enia na, ipá ẹniti o wà ninu rẹ: li ọkàn ẹniti ọ̀na rẹ wà.

6 Awọn ti nla afonifoji omije lọ, nwọn sọ ọ di kanga; akọrọ-òjo si fi ibukún bò o.

7 Nwọn nlọ lati ipá de ipá, ni Sioni ni awọn yọ niwaju Ọlọrun.

8 Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, gbọ́ adura mi ; fi eti si i, Ọlọrun Jakobu.

9 Kiyesi i, Ọlọrun asà wa, ki o si ṣiju wò oju Ẹni-ororo rẹ.

10 Nitori pe ọjọ kan ninu agbala rẹ sanju ẹgbẹrun ọjọ lọ. Mo fẹ ki nkuku ma ṣe adena ni ile Ọlọrun mi, jù lati ma gbe agọ ìwa-buburu.

11 Nitori Oluwa Ọlọrun li õrun ati asà: Oluwa yio fun ni li ore-ọfẹ ati ogo: kò si ohun rere ti yio fà sẹhin lọwọ awọn ti nrìn dede.

12 Oluwa awọn ọmọ-ogun, ibukún ni fun oluwarẹ̀ na ti o gbẹkẹle ọ.

## ORIN 85.

OLUWA, iwọ ti nṣe oju rere si ilẹ rẹ: iwọ ti mu igbekun Jakobu pada bọ̀.

2 Iwọ ti dari aiṣedede awọn enia rẹ jì, iwọ ti bò gbogbo ẹ̀ṣẹ wọn mọlẹ.

3 Iwọ ti mu gbogbo ibinu rẹ kuro: iwọ ti yipada kuro ninu gbigbona ibinu rẹ.

4 Yi wa pada, Ọlọrun igbala wa, ki o si mu ibinu rẹ si wa ki o dá.

5 Iwọ o binu si wa titi lai? iwọ o fà ibinu rẹ jade lati irandiran ?

6 Iwọ kì yio tun mu wa sọji: ki awọn enia rẹ ki o ma yọ̀ ninu rẹ?

7 Oluwa fi ãnu rẹ hàn fun wa, ki o si fun wa ni igbala rẹ.

8 Emi o gbọ́ bi Ọlọrun Oluwa yio ti wi: nitoriti yio sọ alafia si awọn enia rẹ̀, ati si awọn enia mimọ́ rẹ̀ : ṣugbọn ki nwọn ki o má tun pada si were.

9 Nitõtọ igbala rẹ̀ sunmọ́ awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀ ; ki ogo ki o le ma gbé ilẹ wa.

10 Ãnu ati otitọ padera ; ododo ati alafią ti fi ẹnu kò ara wọn li ẹnu.

11 Otitọ yio rú jade lati ilẹ wá: ododo yio si bojuwò ilẹ lati ọrun wá.

12 Nitõtọ Oluwa yio funni li eyi ti o dara; ilẹ wa yio si ma mu asunkun rẹ̀ wá.

13 Ododo yio ṣãju rẹ̀ ; yio si fi ipasẹ rẹ̀ ṣe ọ̀na.

## ORIN 86.

OLUWA, dẹ eti rẹ silẹ, gbohùn mi: nitori ti emi ṣe talaka ati alaini.

2 Pa ọkàn mi mọ́; nitori emi li ẹniti iwọ ṣe ojurere fun: iwọ, Ọlọrun mi, gbà ọmọ ọdọ rẹ ti o gbẹkẹle ọ.

3 Ṣãnu fun mi, Oluwa: nitori iwọ li emi nkepè lojojumọ.

4 Mu ọkàn iranṣẹ rẹ yọ̀: Oluwa, nitori iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si.

5 Nitori iwọ, Oluwa, o ṣeun, o si mura ati dariji; o si pọ̀ li ãnu fun gbogbọ awọn ti nkepè ọ.

6 Oluwa, fi eti si adura mi ; ki o si fiye si ohùn ẹ̀bẹ mi.

7 Li ọjọ ipọnju mi, emi o kepè ọ: nitori ti iwọ o da mi lohùn.

8 Oluwa, ninu awọn oriṣa kò si ọkàn ti o dabi rẹ, bẹ̃ni kò si iṣẹ kan ti o dabi iṣẹ rẹ.

9 Gbogbo awọn orilẹ-ède ti iwọ da ni yio wá, nwọn o si sìn niwaju rẹ, Oluwa; nwọn o si ma fi ogo fun orukọ rẹ.

10 Nitoripe iwọ pọ̀, iwọ si nṣe ohun iyanu: iwọ nikan li Ọlọrun.

11 Oluwa, kọ́ mi li ọ̀na rẹ; emi o ma rìn ninu otitọ rẹ: mu aiya mi ṣọkan lati bẹ̀ru orukọ rẹ.

12 Emi o yìn ọ, Oluwa Ọlọrun mi, tinutinu mi gbogbo: emi o si ma fi ogo fun orukọ rẹ titi lai.

13 Nitoripe nla li ãnu rẹ si mi: iwọ si ti gbà ọkàn mi lọwọ isa-okú jijin.

14 Ọlọrun, awọn agberaga dide si mi, ati ijọ awọn alagbara nwá ọkàn mi kiri; nwọn kò si fi ọ pè li oju wọn.

15 Ṣugbọn iwọ, Oluwa, li Ọlorun ti o kún fun iyọ́nu, ati olore-ọfẹ, olupamọra, o si pọ̀ li ãnu ati otitọ.

16 Yipada si mi ki o si ṣãnu fun mi; fi ipá rẹ fun iranṣẹ rẹ, ki o si gbà ọmọkọnrin iranṣẹ-birin rẹ là.

17 Fi àmi hàn mi fun rere; ki awọn ti o korira mi ki o le ri i, ki oju ki o le tì

Digitized by Google

wọn, nitori iwọ, Oluwa, li o ti ràn mi lọwọ ti o si tù mi ninu.

## ORIN 87.

IPILẸ rẹ̀ mbẹ lori òke mimọ́ wọnni.
2 Oluwa fẹ ẹnu-ọ̀na Sioni jù gbogbo ibujoko Jakobu lọ.
3 Ohun ogo li a nsọ niti rẹ? Ilu Ọlọrun!
4 Emi o da orukọ Rahabu ati Babeli lãrin awọn ti o mọ̀ mi: kiyesi Filistia ati Tire, pẹlu Etiopia: a bi eleyi nibẹ.
5 Ati ni Sioni li a o wipe: ọkọnrin yi ati ọkọnrin nì li a bi ninu rẹ̀: ati Ọga-ogo tikararẹ̀ ni yio fi ẹsẹ rẹ̀ mulẹ.
6 Oluwa yio kà, nigbati o ba nkọ orukọ awọn enia, pe, a bi eleyi nibẹ.
7 Ati awọn olorin ati awọn ti nlu ohun-elo orin yio wipe: Gbogbo orisun mi mbẹ ninu rẹ.

## ORIN 88.

OLUWA Ọlọrun igbala mi, emi nkigbe lọsan ati loru niwaju rẹ.
2 Jẹ ki adura mi ki o wá si iwaju rẹ: dẹ eti rẹ silẹ si igbe mi.
3 Nitori ti ọkàn mi kún fun ipọnju, ẹmi mi si sunmọ isa-okú.
4 A kà mi pẹlu kún awọn ti o sọkalẹ lọ si ihò: emi dabi ọkọnrin ti kò ni ipá.
5 Ẹniti a kọ̀ silẹ lãrin awọn okú, bi awọn ẹni pipa ti o dubulẹ ni isa-okú, ẹniti iwọ kò ranti mọ́: a si ke wọn kuro nipa ọwọ rẹ.
6 Iwọ ti fi mi le ibi isalẹ ti o jìn julọ, ninu okunkun, ninu ọgbun.
7 Ibinu rẹ lẹ̀ mọ mi lara kikan, iwọ si ti fi riru omi rẹ gbogbo ba mi ja.
8 Iwọ ti mu awọn ojulumọ mi jina si mi; iwọ si sọ mi di irira si wọn; a se mi mọ́, emi kò le jade.
9 Oju mi nkãnu nitori ipọnju: Oluwa, emi ti npè ọ lojojumọ, emi si ti nawọ mi si ọ.
10 Iwọ o fi iṣẹ iyanu rẹ hàn fun okú bi? awọn okú yio ha dide ki nwọn si ma yìn ọ bi?
11 A o ha fi iṣeun ifẹ rẹ hàn ni isa-okú bi? tabi otitọ rẹ ninu iparun?
12 A ha le mọ̀ iṣẹ iyanu rẹ li okunkun bi? ati ododo rẹ ni ilẹ igbagbe?
13 Ṣugbọn iwọ ni mo kigbe si, Oluwa; ati ni kutukutu owurọ li adura mi yio ṣaju rẹ.
14 Oluwa, ẽṣe ti iwọ fi ṣa ọkàn mi tì? ẽṣe ti iwọ fi pa oju rẹ mọ́ kuro lọdọ mi?
15 Iṣẹ́ nṣẹ mi, emi mura ati kú lati igba ewe mi wá: nigbati ẹ̀ru rẹ ba mbà mi, emi di gbere-gbere.
16 Ifẹju ibinu rẹ kọja lara mi; ìbẹru rẹ ti ke mi kuro.
17 Nwọn wá yi mi ka li ọjọ gbogbo bi omi: nwọn yi mi kakiri tan.
18 Olufẹ ati ọrẹ ni iwọ mu jina si mi, ati awọn ojulumọ mi ninu okunkun.

## ORIN 89.

EMI o ma kọrin ãnu Oluwa lailai: ẹnu mi li emi o-ma fi fi otitọ rẹ hàn lati irandiran.
2 Nitori ti emi ti wipe, A o gbé ãnu ró soke lailai: otitọ rẹ ni iwọ o gbé kalẹ li ọrun.
3 Emi ti bá ayànfẹ mi da majẹmu, emi ti bura fun Dafidi, iranṣẹ mi,
4 Irú ọmọ rẹ li emi o gbé kalẹ lailai, emi o si ma gbé itẹ́ rẹ ró lati irandiran,
5 Ọrun yio si ma yìn iṣẹ-iyanu rẹ, Oluwa, otitọ rẹ pẹlu ninu ijọ enia mimọ́ rẹ.
6 Nitori pe, tali o wà li ọrun ti a le fi wé Oluwa? tani ninu awọn ọmọ alagbara, ti a le fi wé Oluwa?
7 Ọlọrun li o ni ìbẹru gidigidi ni ijọ enia mimọ́, o si ni ibuyìn-fun lati ọdọ gbogbo awọn ti o yi i ká.
8 Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, tani Oluwa alagbara bi iwọ? tabi bi otitọ rẹ ti o yi ọ ká.
9 Iwọ li o jọba ibinu okun; nigbati riru omi rẹ̀ dide, iwọ mu u pa rọrọ.
10 Iwọ li o ti ya Rahabu pẹrẹ-pẹrẹ bi ẹniti a pa; iwọ ti fi apa ọwọ́ agbara rẹ tú awọn ọtá rẹ ká.
11 Ọrun ni tirẹ, aiye pẹlu ni tirẹ: aiye ati ẹ̀kun rẹ̀, iwọ li o ti ṣe ipilẹ wọn.
12 Ariwa ati gusù iwọ li o ti da wọn: Taboru ati Hermoni yio ma yọ̀ li orukọ rẹ.
13 Iwọ ni apá agbara: agbara li ọwọ́ rẹ, giga li ọwọ ọtún rẹ.
14 Otitọ ati idajọ ni ibujoko itẹ́ rẹ: ãnu ati otitọ ni yio ma lọ siwaju rẹ.
15 Ibukún ni fun awọn enia ti o mọ̀ ohùn ayọ̀ nì: Oluwa, nwọn o ma rìn ni imọlẹ oju rẹ.
16 Li orukọ rẹ ni nwọn o ma yọ̀ li ọjọ gbogbo: ati ninu ododo rẹ li a o ma gbé wọn leke.
17 Nitori iwọ li ogo agbara wọn: ati ninu ore ojurere rẹ li a o gbé iwo wa soke.
18 Nitori Oluwa li asà wa; Ẹni-Mimọ́ Israeli li ọba wa.
19 Nigbana ni iwọ sọ li oju iran fun



Digitized by Google

ayanfẹ rẹ, o si wipe, Emi ti gbé iranlọwọ
ru ẹni-alagbara; emi ti gbé ẹnikan leke ti
a yàn ninu awọn enia.
20 Emi ti ri Dafidi, iranṣẹ mi; ororo mi
mimọ ni mo ta si i li ori:
21 Nipasẹ ẹniti a o fi ọwọ mi mulẹ: apá
mi pẹlu yio ma mu u li ara le.
22 Ọtá kì yio bère lọdọ rẹ̀; bẽni awọn
ọmọ iwà-buburu kì yio pọn ọ loju.
23 Emi o si lu awọn ọta rẹ̀ bolẹ niwaju
rẹ̀, emi o si yọ awọn ti o korira rẹ̀ li ẹnu.
24 Ṣugbọn otitọ mi ati ãnu mi yio wà
pẹlu rẹ̀; ati li orukọ mi li a o gbé iwo rẹ̀
soke.
25 Emi o gbé ọwọ rẹ̀ le okun, ati ọwọ
ọtún rẹ̀ le odò nla nì.
26 On o kigbe pè mi pe, Iwọ ni baba
mi, Ọlọrun mi, ati apata igbala mi.
27 Emi o si ṣe e li akọbi, Ẹni-giga jù
awọn ọba aiye lọ.
28 Ãnu mi li emi o pamọ fun u lailai,
ati majẹmu mi yio si ba a duro ṣinṣin.
29 Irú-ọmọ rẹ̀ pẹlu li emi o mu pẹ titi,
ati itẹ rẹ̀ bi ọjọ ọrun.
30 Bi awọn ọmọ rẹ̀ ba kọ̀ ofin mi silẹ, ti
nwọn kò si rìn nipa idajọ mi;
31 Bi nwọn ba bà ilana mi jẹ, ti nwọn
kò si pa ofin mi mọ,
32 Nigbana li emi o fi ọgọ bẹ irekọja
wọn wò, ati ẹ̀ṣẹ wọn pẹlu ìna.
33 Ṣugbọn iṣeun-ifẹ mi li emi kì yio gbà
lọwọ rẹ̀, bẽli emi kì yio jẹ ki otitọ mi ki o
yẹ̀.
34 Majẹmu mi li emi kì yio dà, bẽli emi
kì yio yi ohun ti o ti ète mi jade pada.
35 Lẹrinkan ni mo ti fi ìwa-mimọ mi
bura pe, emi kì yio purọ fun Dafidi.
36 Iru-ọmọ rẹ̀ yio duro titi lailai, ati itẹ
rẹ̀ bi õrun niwaju mi.
37 A o fi idi rẹ̀ mulẹ lailai bi òṣupa, ati
bi ẹlẹri otitọ li ọrun.
38 Ṣugbọn iwọ ti ṣa tì, iwọ si korira,
iwọ ti binu si Ẹni-ororo rẹ.
39 Iwọ ti sọ majẹmu iranṣẹ rẹ di ofo:
iwọ ti sọ ade rẹ̀ si ilẹ.
40 Iwọ ti fa ọgba rẹ̀ gbogbo ya: iwọ ti
mu ilu-olodi rẹ̀ di ahoro.
41 Gbogbo awọn ti nkọja lọ li ọna nfi
ṣe ijẹ: on si di ẹ̀gan fun awọn aladugbo
rẹ̀.
42 Iwọ ti gbé ọwọ ọtún awọn ọta rẹ̀
soke; iwọ mu gbogbo awọn ọta rẹ̀ yọ̀.
43 Iwọ si ti yi oju idà rẹ̀ pada pẹlu, iwọ
kò si mu u duro li oju ogun.
44 Iwọ ti mu ogo rẹ̀ tọ, iwọ si wọ itẹ rẹ̀
silẹ-yilẹ.
45 Ọjọ ewe rẹ̀ ni iwọ ke kuru; iwọ fi
itìju bò o.
46 Yio ti pẹ to, Oluwa? iwọ o pa ara rẹ
mọ lailai? ibinu rẹ yio ha jo bi iná bi?
47 Ranti bi ọjọ mi ti kuru to; ẽse ti iwọ
ha da gbogbo enia lasan?
48 Ọkọnrin wo li o wà lãye, ti kì yio ri
ikú? ti yio gbà ọkàn rẹ̀ lọwọ isa-okú.
49 Oluwa, nibo ni iṣeun-ifẹ rẹ atijọ wà,
ti iwọ bura fun Dafidi ninu otitọ rẹ?
50 Oluwa, ranti ẹ̀gan awọn iranṣẹ rẹ, ti
emi nrù li aiya mi lati ọdọ gbogbo ọ̀pọ enia.
51 Ti awọn ọta rẹ fi kẹgàn, Oluwa: ti
nwọn fi ngán ipasẹ Ẹni-ororo rẹ.
52 Olubukún ni Oluwa si i titi lailai.
Amin ati Amin.

---

## IWE IV.

### ORIN 90.

*Adura Mose, enia Ọlọrun.*

OLUWA, iwọ li o ti nṣe ibujoko wa lati
irandiran.
2 Ki a to bí awọn òke nla, ati ki iwọ ki
o to dá ilẹ on aiye, ani lati aiye-raiye, iwọ
li Ọlọrun.
3 Iwọ sọ enia di ibajẹ; iwọ si wipe, Ẹ
pada wá, ẹnyin ọmọ enia.
4 Nitoripe igbati ẹgbẹrun ọdun ba kọja
li oju rẹ, bi aná li o ri, ati bi igba iṣọ kan
li oru.
5 Iwọ kó wọn lọ bi ẹnipe ni ṣiṣan-omi;
nwọn dabi orun; ni kutukutu nwọn dabi
koriko ti o dagba soke.
6 Ni kutukutu o li àwọ lara, o si dàgba
soke, li asalẹ a ke e lulẹ, o si rọ.
7 Nitori awa di egbé nipa ibinu rẹ, ati
nipa ibinu rẹ ara kò rọ̀ wa.
8 Iwọ ti gbé ẹ̀ṣẹ wa ka iwaju rẹ, ohun
ìkọkọ wa mbẹ ninu imọlẹ iwaju rẹ.
9 Nitori ọjọ wa gbogbo nyipo lọ ninu
ibinu rẹ: awa nlo ọjọ wa bi alá ti a nrọ.
10 Adọrin ọdun ni iye ọjọ ọdun wa; bi
o si ṣepe nipa ti agbara, bi nwọn ba to
ọgọrin ọdun, agbara wọn lãla on ibinujẹ
ni; nitori pe a kì o pẹ ke e kuro, awa a si
fò lọ.
11 Tali o mọ̀ agbara ibinu rẹ? gẹgẹ bi
ẹ̀ru rẹ, bẽni ibinu rẹ.
12 Bẽni ki iwọ ki o kọ́ wa lati ma ka iye
ọjọ wa, ki awa ki o le fi ọkàn wa sipa
ọgbọ́n.
13 Pada, Oluwa, yio ti pẹ to? yi ọkàn
pada nitori awọn ọmọ-ọdọ rẹ.

Digitized by Google

14 Fi ãnu rẹ tẹ́ wa li ọrùn ni kutukutu; ki awa ki o le ma yọ̀, ati ki inu wa ki o le ma dùn li ọjọ wa gbogbo.

15 Mu inu wa dùn bi iye ọjọ ti iwọ pọ́n wa loju, ati iye ọdun ti awa ti nri buburu.

16 Jẹ ki iṣẹ rẹ ki o hàn si awọn ọmọ-ọdọ rẹ, ati ogo rẹ si awọn ọmọ wọn.

17 Jẹ ki ẹwà Oluwa Ọlọrun wa ki o wà lara wa: ki iwọ ki o si fi idi iṣẹ ọwọ wa mulẹ lara wa, bẽni iṣẹ ọwọ wa ni ki iwọ ki o fi idi rẹ̀ mulẹ.

## ORIN 91.

ENITI o joko ni ibi ìkọkọ Ọga-ogo ni yio ma gbe abẹ ojiji Olodumare.

2 Emi o wi fun Ọlọrun pe, Iwọ li àbo ati odi mi; Ọlọrun mi, ẹniti emi gbẹkẹle.

3 Nitõtọ on o gbà ọ ninu ikẹkun awọn pẹyẹpẹyẹ, ati ninu àjakalẹ-àrun buburu.

4 Yio fi iyẹ́ rẹ̀ bò ọ, abẹ iyẹ́-apa rẹ̀ ni iwọ o si gbẹkẹle: otitọ rẹ̀ ni yio ṣe asà ati apata rẹ.

5 Iwọ kì yio bẹ̀ru nitori ẹ̀ru oru; tabi fun ọfa ti nfo li ọsán;

6 Tabi fun àjakalẹ-àrun ti nrìn kiri li okunkun, tabi fun iparun ti nrun-ni li ọsángangan.

7 Ẹgbẹrun yio ṣubu li ẹgbẹ rẹ, ati ẹgbarun li apa ọtún rẹ: ṣugbọn kì yio sunmọ ọdọ rẹ.

8 Kiki oju rẹ ni iwọ o ma fi ri, ti o si ma fi wo ère awọn enia buburu.

9 Nitori iwọ, Oluwa, ni iṣe ãbo mi, iwọ ti fi Ọga-ogo ṣe ibugbe rẹ.

10 Buburu kan kì yio ṣubu lu ọ, bẹ̃li arunkarun kì yio sunmọ ile rẹ.

11 Nitori ti yio fi aṣẹ fun awọn angeli rẹ̀ nitori rẹ, lati pa ọ mọ́ li ọ̀na rẹ gbogbo.

12 Nwọn o gbé ọ soke li ọwọ́ wọn, ki iwọ ki o má ba fi ẹsẹ rẹ gbun okuta.

13 Iwọ o kọja lori kiniun ati pamọlẹ: ẹgbọrọ kiniun ati ejò-nla ni iwọ o fi ẹsọ tẹ̀-mọlẹ.

14 Nitori ti o fẹ ifẹ rẹ̀ si mi, nitorina li emi o ṣe gbà a: emi o gbé e leke, nitori ti o mọ̀ orukọ mi.

15 On o pè orukọ mi, emi o si da a lohùn: emi o pẹlu rẹ̀ ninu ipọnju, emi o gbà a, emi o si bu ọlá fun u.

16 Ẹmi gigun li emi o fi tẹ́ ẹ lọrun, emi o si fi igbala mi hàn a.

## ORIN 92.

*Orin fun ọjọ isimi.*

OHUN rere ni lati ma fi ọpẹ fun Oluwa, ati lati ma kọrin si orukọ rẹ, Oga ogo:

2 Lati ma fi iṣeun ifẹ rẹ hàn li owurọ, ati otitọ rẹ li alalẹ.

3 Lara ohun-elo orin olokùn mẹwa, ati lara ohun-elo orin mimọ́: lara duru pẹlu iró ti o ni ironu.

4 Nitori iwọ, Oluwa, li o ti mu mi yọ̀ nipa iṣẹ rẹ: emi o ma kọrin iyìn nitori iṣẹ ọwọ rẹ.

5 Oluwa, iṣẹ rẹ ti tobi to! ìro-inu rẹ jinlẹ gidigidi.

6 Ope enia kò mọ̀; bẹ̃li oye eyi kò ye aṣiwere enia.

7 Nigbati awọn enia buburu ba rú bi koriko, ati igbati gbogbo awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ ba ngberú: ki nwọn ki o le run lailai ni:

8 Ṣugbọn iwọ, Oluwa li ẹniti o ga titi lai.

9 Sa wò o, awọn ọta rẹ, Oluwa, sa wò o, awọn ọta rẹ yio ṣegbe; gbogbo oniṣẹ ẹ̀ṣẹ li a o tuka.

10 Ṣugbọn iwo mi ni iwọ o gbé ga bi iwo agbanrere; ororo titun li a o ta si mi lori.

11 Oju mi pẹlu yio ri ifẹ mi lara awọn ọta mi, eti mi yio si ma gbọ́ ifẹ mi si awọn enia buburu ti o dide si mi.

12 Olododo yio gbà bi igi ọpẹ: yio dàgba bi igi kedari Lebanoni.

13 Awọn ẹniti a gbin ni ile Oluwa, yio gbà ni agbala Ọlọrun wa.

14 Nwọn o ma so eso sibẹ ninu ogbó wọn: nwọn o sanra, nwọn o ma tutù nini;

15 Lati fi hàn pe, Ẹni diduro-ṣinṣin ni Oluwa: on li apata mi, kò si si aiṣododo kan ninu rẹ̀.

## ORIN 93.

OLUWA jọba, ọla-nla li o wọ li aṣọ; agbara ni Oluwa wọ̀ li aṣọ, o fi di ara rẹ̀ li amure: o si fi idi aiye mulẹ, ti kì yio fi le yi.

2 Lati igba atijọ li a ti fi idi itẹ́ rẹ kalẹ, ati aiye-raiye ni Iwọ.

3 Iṣan-omi gbé ohùn wọn soke, Oluwa, iṣan-omi gbé ohùn wọn soke; iṣan-omi gbé riru omi wọn soke.

4 Oluwa li ologo, o li ogo jù ariwo omi pupọ lọ, jù riru omi nla, ani jù agbara riru omi okun lọ.

5 Otitọ li ẹri rẹ: ìwa-mimọ́ li o yẹ ile rẹ lailai, Oluwa.

## ORIN 94.

OLUWA, Ọlọrun ẹsan; Ọlọrun ẹsan, fi ara rẹ hàn.

2 Gbé ara rẹ soke, iwọ onidajọ aiye: san ẹsan fun awọn agberaga.

Digitized by Google

3 Oluwa, yio ti pẹ to ti awọn enia bu-
buru, yio ti pẹ to ti awọn enia buburu yio
fi ma leri ?
4 Nwọn o ti ma dà ọ̀rọ nù ti nwọn o
ma sọ ohun lile pẹ to ? ti gbogbo onișẹ ẹ̀ṣẹ
yio fi ma fi ara wọn leri.
5 Oluwa, nwọn fọ́ awọn enia rẹ tutu,
nwọn si nyọ awọn enia-ini rẹ lẹnu.
6 Nwọn pa awọn opó ati alejo, nwọn si
pa awọn ọmọ alaini-baba.
7 Sibẹ nwọn wipe, Oluwa kì yio ri i,
bẽli Ọlọrun Jakobu kì yio kà a si,
8 Ki oye ki o ye nyin, ẹnyin ope ninu
awọn enia : ati ẹnyin aṣiwere, nigbawo li
ẹnyin o gbọ́n ?
9 Ẹniti o gbin eti, o le ṣe alaigbọ́ bi ?
ẹniti o da oju, o ha le ṣe alairiran ?
10 Ẹniti nnà awọn orilẹ-ède, o ha le ṣe
alaiṣe olutọ́ ? on li ẹniti nkọ́ enia ni ìmọ.
11 Oluwa mọ̀ ìro-inu enia pe : asan ni
nwọn.
12 Ibukún ni fun enia na ẹniti iwọ nà,
Oluwa, ti iwọ si kọ́ lati inu ofin rẹ wá ;
13 Ki iwọ ki o le fun u ni isimi kuro li
ọjọ ibi, titi a o fi wà iho silẹ fun enia
buburu.
14 Nitoripe Oluwa kì yio ṣa awọn enia
rẹ̀ tì, bẽni kì yio kọ̀ awọn enia-ini rẹ̀ silẹ.
15 Ṣugbọn idajọ yio pada si ododo : gbo-
gbo ọlọkàn diduro ni yio si ma tọ̀ ọ lẹhin.
16 Tani yio dide si awọn oluṣe buburu
fun mi ? tabi tani yio dide si awọn onișẹ
ẹ̀ṣẹ fun mi ?
17 Bikoṣe bi Oluwa ti ṣe oluranlọwọ mi ;
ọkàn mi fẹrẹ joko ni idakẹ.
18 Nigbati mo wipe, Ẹsẹ mi yọ́ ? Oluwa,
ãnu rẹ dì mi mu.
19 Ninu ọ̀pọlọpọ ibinujẹ mi ninu mi,
itunu rẹ li o nmu inu mi dùn.
20 Itẹ́ ẹ̀ṣẹ ha le ba ọ kẹgbẹ pọ̀, ti nfi
ofin dimọ ìwa-ika ?
21 Nwọn kó ara wọn jọ pọ̀ si ọkàn olo-
dodo, nwọn si da ẹ̀jẹ alaiṣẹ lẹbi.
22 Ṣugbọn Oluwa li àbo mi ; Ọlọrun mi
si li apata àbo mi,
23 On o si mu ẹ̀ṣẹ wọn bọ̀ sori ara wọn,
yio si ke wọn kuro ninu ìwa-buburu wọn :
Oluwa Ọlọrun wa, yio ke wọn kuro.

## ORIN 95.

EWÁ, ẹ jẹ ki a kọrin si Oluwa : ẹ jẹ ki
a hó iho ayọ̀ si apata igbala wa.
2 Ẹ jẹ ki a fi ọpẹ wá si iwaju rẹ̀, ki a si
fi orin mimọ́ hó iho ayọ̀ si ọdọ rẹ̀.
3 Nitori Oluwa, Ọlọrun ti o tobi ni, ati
Ọba ti o tobi jù gbogbo oriṣa lọ,
4 Ni ikawọ ẹniti ibi ọgbun ilẹ wà : giga
awọn òke nla ni tirẹ̀ pẹlu.
5 Tirẹ̀ li okun, on li o si dá a : ọwọ rẹ̀
li o si dá iyangbẹ ilẹ.
6 Ẹ wá, ẹ jẹ ki a wọle, ki a tẹriba : ẹ jẹ
ki a kunlẹ niwaju Oluwa, Ẹlẹda wa.
7 Nitori on li Ọlọrun wa ; awa si li enia
papa rẹ̀, ati agutan ọwọ rẹ̀. Loni bi ẹnyin
o ba gbọ́ ohùn rẹ̀,
8 Ẹ má sé aiya nyin le, bi ti Meriba ati
bi ọjọ na ni Massa, li aginju.
9 Nigbati awọn baba nyin dan mi wò,
ti nwọn wadi mi, ti nwọn si ri iṣẹ mi.
10 Ogoji ọdun tọ̀tọ ni inu mi fi bajẹ si
iran na, mo ni, Enia ti o ṣina li aiya ni
nwọn, nwọn kò si mọ̀ ọ̀na mi :
11 Awọn ẹniti mo si bura fun ni ibinu
mi pe, bi nwọn o ti wọ ibi isimi mi.

## ORIN 96.

EKỌRIN titun si Oluwa : ẹ kọrin si
Oluwa gbogbo aiye.
2 Ẹ kọrin si Oluwa, fi ibukún fun orukọ
rẹ̀ ; ẹ ma fi igbala rẹ̀ hàn lati ọjọ de ọjọ.
3 Sọ̀rọ ogo rẹ̀ lãrin awọn keferi, ati iṣẹ
iyanu rẹ̀ lãrin gbogbo enia.
4 Nitori ti Oluwa tobi, o si ni iyìn pupọ̀-
pupọ̀ : on li o ni ìbẹru jù gbogbo oriṣa lọ.
5 Nitori pe gbogbo oriṣa orilẹ-ède asan
ni nwọn : ṣugbọn Oluwa li o da ọrun.
6 Ọlá ati ọla-nla li o wà niwaju rẹ̀ : ipa
ati ẹwà mbẹ ninu ibi mimọ́ rẹ̀.
7 Ẹ fi fun Oluwa, ẹnyin ibatan enia, ẹ
fi ogo ati ipá fun Oluwa.
8 Ẹ fi ogo fun orukọ Oluwa : mu ọrẹ wá,
ki ẹ si wá si agbala rẹ̀.
9 Ẹ ma sìn Oluwa ninu ẹwà ìwamimọ́ :
ẹ wariri niwaju rẹ̀, gbogbo aiye.
10 Ẹ wi lãrin awọn keferi pe, Oluwa
jọba : nitõtọ a o fi idi aiye mulẹ ti kì yio
le yẹ̀ : on o fi ododo ṣe idajọ enia.
11 Jẹ ki ọrun ki o yọ̀, jẹ ki inu aiye ki
o dùn ; jẹ ki okun ki o ma ho pẹlu ikún rẹ̀.
12 Jẹ ki oko ki o kún fun ayọ̀, ati ohun
gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀ : nigbana ni gbogbo
igi igbo yio ma yọ̀.
13 Niwaju Oluwa : nitoriti mbọwa, ni-
tori ti mbọwa ṣe idajọ aiye : yio fi ododo
ṣe idajọ aiye, ati ti enia ni yio fi otitọ rẹ̀ ṣe.

## ORIN 97.

OLUWA jọba ; ki aiye ki o yọ̀ ; jẹ ki
inu ọ̀pọlọpọ erekuṣu ki o dùn.
2 Awọsanma ati okunkun yi i ka : odo-
do ati idajọ ni ibujoko itẹ́ rẹ̀.

Digitized by Google

3 Iná ṣaju rẹ̀, o si jo awọn ọta rẹ̀ yika
kiri.
4 Manamana rẹ̀ kọ imọlẹ si aiye: aiye
ri i, o si wariri.
5 Awọn òke nyọ́ bi ida niwaju Oluwa,
niwaju Oluwa gbogbo aiye:
6 Ọrun fi ododo rẹ̀ hàn, gbogbo orilẹ-
ède si ri ogo rẹ̀.
7 Oju yio tì gbogbo awọn ti nsìn ere
fifin, ẹniti nfi ere ṣe ileri ara wọn: ẹ ma
sìn i, gbogbo ẹnyin ọlọrun.
8 Sioni gbọ́, inu rẹ̀ si dùn; awọn ọmọ-
birin Juda si yọ̀, Oluwa, nitori idajọ rẹ.
9 Nitoripe Iwọ Olúwa, li o ga jù gbo-
gbo aiye lọ: Iwọ li a gbé ga jù gbogbo
oriṣa lọ.
10 Ẹnyin ti o fẹ Oluwa, ẹ korira ibi:
o pa ọkàn awọn enia mimọ́ rẹ̀ mọ́: o gbà
wọn li ọwọ awọn enia buburu.
11 A funrugbin imọlẹ fun olododo, ati
inu didùn fun alaiya diduro.
12 Ẹ yọ̀ niti Oluwa, ẹnyin olododo; ki
ẹ si ma dupẹ ni iranti ìwa-mimọ́ rẹ̀.

## ORIN 98.

EKỌRIN titun si Oluwa; nitoriti o ti
ṣe ohun iyanu: ọwọ ọtún rẹ̀, ati apa
rẹ̀ mimọ́ li o ti mu igbala wa fun ara rẹ̀.
2 Oluwa ti sọ igbala rẹ̀ di mimọ̀: ododo
rẹ̀ li o ti fi hàn nigbangba li oju awọn
keferi.
3 O ti ranti ãnu rẹ̀ ati otitọ rẹ̀ si awọn
ara ile Israeli: gbogbo opin aiye ti ri igba-
la Ọlọrun wa.
4 Ẹ ho iho ayọ̀ si Oluwa, gbogbo aiye:
ẹ ho yè, ẹ yọ̀, ki ẹ si ma kọrin iyìn.
5 Ẹ ma fi duru kọrin si Oluwa, ati duru
pẹlu ohùn orin-mimọ́.
6 Pẹlu ipè ati ohùn fere, ẹ ho iho ayọ̀
niwaju Oluwa, Ọba.
7 Jẹ ki okun ki o ma ho pẹlu ikún rẹ̀;
aiye, ati awọn ti mbẹ ninu rẹ̀.
8 Jẹ ki odò ki o ma ṣapẹ, ki awọn òke
ki o ma ṣe ajọyọ̀.
9 Niwaju Oluwa; nitori ti mbọwa iṣe
idajọ aiye: pẹlu ododo ni yio fi ṣe idajọ
aiye, ati awọn orilẹ-ède li aiṣègbe.

## ORIN 99.

OLUWA jọba; jẹ ki awọn enia ki o wari-
ri: o joko lori awọn kerubu; ki aiye
ki o ta gbọ̀ngbọ̀n.
2 Oluwa tobi ni Sioni: o si ga jù gbo-
gbo orilẹ-ède lọ.
3 Ki nwọn ki o yìn orukọ rẹ ti o tobi, ti
o si li ẹ̀ru; mimọ́ li on.
4 Agbara ọba fẹ idajọ pẹlu, iwọ fi idi
aiṣegbe mulẹ; iwọ nṣe idajọ ati ododo ni
Jakobu.
5 Ẹ gbé Oluwa Ọlọrun wa ga, ki ẹ si
foribalẹ nibi apoti itisẹ rẹ̀: mimọ́ li on.
6 Mose ati Aaroni ninu awọn alufa rẹ̀,
ati Samueli ninu awọn ti npè orukọ rẹ̀:
nwọn ke pè Oluwa, o si da wọn lohùn.
7 O ba wọn sọ̀rọ ninu ọwọ̀n awọsanma:
nwọn pa ẹri rẹ̀ mọ́ ati ilana ti o fi fun wọn.
8 Iwọ da wọn lohùn, Oluwa Ọlọrun wa:
iwọ li Ọlọrun ti o dariji wọn, ti o si san
ẹsan iṣẹ wọn.
9 Ẹ gbé Oluwa Ọlọrun wa ga, ki ẹ si ma
sìn nibi òke mimọ́ rẹ̀; nitori Oluwa Ọlọrun
wa mimọ́ ni.

## ORIN 100.

EHO iho ayọ̀ si Oluwa, ẹnyin ilẹ gbogbo.
2 Ẹ fi ayọ̀ sìn Oluwa: ẹ wá ti ẹnyin
ti orin si iwaju rẹ̀.
3 Ki ẹnyin ki o mọ̀ pe Oluwa, on li
Ọlọrun: on li o dá wa, tirẹ̀ li awa; awa li
enia rẹ̀, ati agutan papa rẹ̀.
4 Ẹ lọ si ẹnu ọ̀na rẹ̀ ti ẹnyin ti ọpẹ, ati
si agbala rẹ̀ ti ẹnyin ti iyìn: ẹ ma dupẹ
fun u, ki ẹ si ma fi ibukún fun orukọ rẹ̀.
5 Nitori ti Oluwa pọ̀ li ore; ãnu rẹ̀ kò
nipẹkun; ati otitọ rẹ̀ lati iran-diran

## ORIN 101.

EMI o kọrin ãnu ati ti idajọ: Oluwa, si ọ
li emi o ma kọrin.
2 Emi o ma rìn ìrin mi pẹlu ọgbọ́n li ọ̀na
pipé. Nigbawo ni iwọ o tọ̀ mi wá! emi o
ma rìn ninu ile mi pẹlu aiya pipé.
3 Emi ki yio gbé ohun buburu siwaju
mi: emi korira iṣẹ awọn ti o yapa, kì yio
fi ara mọ mi.
4 Aiya ṣiṣo yio kuro lọdọ mi: emi kì
yio mọ̀ enia buburu.
5 Ẹnikẹni ti o ba nsọ̀rọ ẹnikeji rẹ̀ lẹhin,
on li emi o ke kuro: ẹniti o ni ìwò giga
ati igberaga aiya, on li emi kì yio jẹ fun.
6 Oju mi yio wà lara awọn olõtọ, ki
nwọn ki o le ma ba mi gbe: ẹniti o ba nrìn
li ọ̀na pipé, on ni o ma sìn mi.
7 Ẹniti o ba nṣe ẹ̀tan, kì o gbe inu ile
mi: ẹniti o ba nṣeke kì yio duro niwaju
mi.
8 Lojojumọ li emi o ma run gbogbo enia
buburu ilẹ na; ki emi ki o le ke gbogbo
oluṣe buburu kuro ni ilu Oluwa.

Digitized by Google

## ORIN 102.

*Adura olupọnju, nigbati o ni ibinujẹ, ti o si tu aroye rẹ̀ jade niwaju Oluwa.*

GBỌ adura mi, Oluwa, ki o si jẹ ki igbe mi ki o wá sọdọ rẹ.
2 Máṣe pa oju rẹ mọ́ kuro lara mi li ọjọ ti emi wà ninu ipọnju ; dẹ eti rẹ si mi : li ọjọ ti mo ba pè, da mi lohùn lọgan.
3 Nitori ti ọjọ mi run bi ẽfin, egungun mi si jona bi àro.
4 Aiya mi lù, o si rọ bi koriko ; tobẽ ti mo gbagbe lati jẹ onjẹ mi.
5 Nitori ohùn ikerora mi, egungun mi lẹ̀ mọ ẹran-ara mi.
6 Emi dabi ẹiyẹ ofú ni iju : emi dabi owiwi ibi ahoro.
7 Emi nṣọra, emi dabi ologoṣẹ nikan li ori ile.
8 Awọn ọta mi ngàn mi li ọjọ gbogbo ; ati awọn ti nṣe ikanra si mi, nwọn fi mi bu.
9 Emi sa jẹ ẽru bi onjẹ, emi si dà ohun mimu mi pọ̀ pẹlu omije.
10 Nitori ikannu ati ibinu rẹ ; nitori iwọ ti gbé mi soke, iwọ si gbé mi ṣanlẹ.
11 Ọjọ mi dabi ojiji ti o nfà sẹhin ; emi si nrọ bi koriko.
12 Ṣugbọn iwọ, Oluwa, ni yio duro lailai ; ati iranti rẹ lati iran de iran.
13 Iwọ o dide, iwọ o ṣãnu fun Sioni : nitori igba ati ṣe oju-rere si i, nitõtọ, àkoko na de.
14 Nitori ti awọn iranṣẹ rẹ ṣe inu didùn si okuta rẹ̀, nwọn si kãnu erupẹ rẹ̀.
15 Bẽli awọn keferi yio ma bẹru orukọ Oluwa, ati gbogbo ọba aiye yio ma bẹru ogo rẹ.
16 Nigbati Oluwa yio gbé Sioni ró, yio farahan ninu ogo rẹ̀.
17 Yio juba adura awọn alaini, kì yio si gàn adura wọn.
18 Eyi li a o kọ fun iran ti mbọ̀ ; ati awọn enia ti a o da yio ma yìn Oluwa.
19 Nitori ti o wò ilẹ lati òke ibimimọ́ rẹ̀ wá ; lati ọrun wá ni Oluwa bojuwo aiye ;
20 Lati gbọ́ irora ara-tubu ; lati tú awọn ti a yàn si ikú silẹ ;
21 Lati sọ orukọ Oluwa ni Sioni, ati iyìn rẹ̀ ni Jerusalemu.
22 Nigbati a kó awọn enia jọ pọ̀ ati awọn ijọba, lati ma sìn Oluwa.
23 O rẹ̀ agbara mi silẹ li ọ̀na ; o mu ọjọ mi kuru.
24 Emi si wipe, Ọlọrun mi, máṣe mu mi
kuro li agbedemeji ọjọ mi : lati iran-diran li ọdun rẹ.
25 Lati igba atijọ ni iwọ ti fi ipilẹ aiye sọlẹ : ọrun si ni iṣẹ ọwọ rẹ,
26 Nwọn o ṣegbe, ṣugbọn Iwọ o duro ; nitõtọ gbogbo wọn ni yio di ogbó bi aṣọ ; bi ẹ̀wu ni iwọ o pàrọ wọn, nwọn o si pàrọ.
27 Ṣugbọn bakanna ni Iwọ, ọdun rẹ kò li opin.
28 Awọn ọmọ awọn iranṣẹ rẹ yio duro pẹ, a o si fi ẹsẹ iru-ọmọ wọn mulẹ niwaju rẹ.

## ORIN 103.

FI ibukún fun Oluwa, iwọ ọkàn mi, ati gbogbo ohun ti o wà ninu mi, fi ibukún fun orukọ rẹ̀ mimọ́.
2 Fi ibukún fun Oluwa, iwọ ọkàn mi, má si ṣe gbagbe gbogbo ore rẹ̀ :
3 Ẹniti o dari gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ jì ; ẹniti o si tan gbogbo àrun rẹ,
4 Ẹniti o ra ẹmi rẹ kuro ninu iparun ; ẹniti o fi iṣeun-ifẹ ati iyọ́nu de ọ li ade :
5 Ẹniti o fi ohun didara tẹ́ ọ lọrun : bẽni igba ewe rẹ di ọtun bi ti idì.
6 Oluwa ṣe ododo ati idajọ fun gbogbo awọn ti a nilara.
7 O fi ọ̀na rẹ̀ hàn fun Mose, iṣe rẹ̀ fun awọn ọmọ Israeli.
8 Oluwa li alãnu ati olõre, o lọra ati binu, o si pọ̀ li ãnu.
9 On kì ibaniwi nigbagbogbo : bẽni kì ipa ibinu rẹ̀ mọ́ lailai.
10 On kì iṣe si wa gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ wa ; bẽni kì isan a fun wa gẹgẹ bi aiṣedede wa.
11 Nitori pe, bi ọrun ti ga si ilẹ, bẽli ãnu rẹ̀ tobi si awọn ti o bẹru rẹ̀.
12 Bi ila-õrun ti jina si ìwọ-õrun, bẽli o mu irekọja wa jina kuro lọdọ wa.
13 Bi baba ti iṣe iyọ́nu si awọn ọmọ, bẽli Oluwa nṣe iyọ́nu si awọn ti o bẹru rẹ̀.
14 Nitori ti o mọ̀ ẹda wa ; o ranti pe erupẹ ni wa.
15 Bi o ṣe ti enia ni, ọjọ rẹ̀ dabi koriko: bi itana eweko igbẹ bẽli o gbilẹ.
16 Nitori ti afẹfẹ fẹ kọja lọ lori rẹ̀, kò sì si mọ́ ; ibujoko rẹ̀ kò mọ̀ ọ mọ́.
17 Ṣugbọn ãnu Oluwa lati aiye-raiye ni lara awọn ti o bẹru rẹ̀, ati ododo rẹ̀ lati ọmọ de ọmọ :
18 Si awọn ti o pa majẹmu rẹ̀ mọ́, ati si awọn ti o ranti ofin rẹ̀ lati ṣe wọn.
19 Oluwa ti pèse itẹ́ rẹ̀ ninu ọrun ; ijọba rẹ̀ li o si bori ohun gbogbo ;
20 Ẹ fi ibukún fun Oluwa, ẹnyin angeli

Digitized by Google

rẹ̀, ti o pọ̀ ni ipa ti nṣe ofin rẹ̀, ti nfi eti si
ohùn ọ̀rọ rẹ̀.
21 Ẹ fi ibukún fun Oluwa, ẹnyin ọmọ-
ogun rẹ̀ gbogbo; ẹnyin iranṣẹ rẹ̀, ti nṣe
ifẹ rẹ̀.
22 Ẹ fi ibukún fun Oluwa, gbogbo iṣẹ
rẹ̀ ni ibi gbogbo ijọba rẹ̀: fi ibukún fun
Oluwa, iwọ ọkàn mi.

## ORIN 104.

FI ibukún fun Oluwa, iwọ ọkàn mi. Olu-
wa, Ọlọrun mi, iwọ tobi jọjọ: ọlá ati
ọla-nla ni iwọ wọ̀ li aṣọ.
2 Ẹniti o fi imọlẹ bora bi aṣọ: ẹniti o ta
ọrun bi aṣọ tita:
3 Ẹniti o fi omi ṣe ìti igi-àja iyẹwu rẹ̀:
ẹniti o ṣe awọsanma ni kẹkẹ̀ rẹ̀, ẹniti o
nrìn lori apa iyẹ afẹfẹ:
4 Ẹniti o ṣe ẹfufu ni onṣẹ rẹ̀; ati ọwọ-
iná ni iranṣẹ rẹ̀.
5 Ẹniti o fi aiye sọlẹ lori ipilẹ rẹ̀, ti kò
le ṣipò pada lailai.
6 Iwọ fi ibu omi bò o mọlẹ bi aṣọ: awọn
omi duro lori òke nla.
7 Nipa ibawi rẹ nwọn sá; nipa ohùn
ãra rẹ, nwọn yara lọ.
8 Awọn òke nla nru soke; awọn afoni-
foji nsọkalẹ si ibi ti iwọ ti fi lelẹ fun wọn.
9 Iwọ ti pa àla kan ki nwọn ki o má le
kọja rẹ̀; ki nwọn ki o má tun pada lati bò
aiye mọlẹ.
10 Iwọ ran orisun si afonifọji, ti nṣàn
larin awọn òke.
11 Awọn ni nfi omi mimu fun gbogbo
ẹranko igbẹ: awọn kẹtẹkẹtẹ igbẹ npa oungbẹ
wọn;
12 Lẹba wọn li awọn ẹiyẹ oju-ọrun yio
ni ile wọn, ti nkọrin lãrin ẹka igi.
13 O mbomi rin awọn òke lati iyẹwu rẹ̀
wá: ère iṣẹ ọwọ rẹ tẹ́ aiye lọrun.
14 O mu koriko dagba fun ẹran, ati
ewebẹ fun ìlo enia: ki o le ma mu onjẹ
jade lati ilẹ wá;
15 Ati ọti-waini ti imu inu enia dùn, ati
oróro ti imu oju rẹ̀ dan, ati onjẹ ti imu
enia li aiya le.
16 Igi Oluwa kún fun oje, igi kedari
Lebanoni, ti o ti gbìn.
17 Nibiti awọn ẹiyẹ ntẹ́ itẹ́ wọn: bi o
ṣe ti àkọ ni, igi firi ni ile rẹ̀.
18 Awọn òke giga li àbo fun awọn ewurẹ
igbẹ: ati awọn apata fun awọn ehoro.
19 O da oṣupa fun akokò: õrùn mọ̀
akokò ìwọ rẹ̀.
20 Iwọ ṣe òkunkun, o si di oru: ninu
eyiti gbogbo ẹranko igbo nrìn kiri.
21 Awọn ẹgbọrọ kiniun ndún si ohun
ọdẹ wọn, nwọn si nwá onjẹ wọn lọwọ
Ọlọrun.
22 Õrùn là, nwọn kó ara wọn jọ, nwọn
dubulẹ ninu iho wọn.
23 Enia jade lọ si iṣẹ rẹ̀ ati si lãla rẹ̀ titi
di aṣalẹ.
24 Oluwa, iṣẹ rẹ ti pọ̀ to! ninu ọgbọ́n
ni iwọ ṣe gbogbo wọn: aiye kún fun ẹ̀da rẹ.
25 Bẹ̃li okun yi ti o tobi, ti o si ni ibò,
nibẹ ni ohun ainiye nrakò, ati ẹran kekere
ati nla.
26 Nibẹ li ọkọ̀ nrìn: nibẹ ni lefiatani nì
wà, ti iwọ da lati ma ṣe ariya ninu rẹ̀.
27 Gbogbo wọnyi li o duro tì ọ; ki iwọ
ki o le ma fun wọn li onjẹ wọn li akokò
wọn.
28 Eyi ti iwọ fi fun wọn ni nwọn nkó:
iwọ ṣí ọwọ rẹ, a si fi ohun rere tẹ́ wọn
lọrùn.
29 Iwọ pa oju rẹ mọ́, ara kò rọ̀ wọn: iwọ
gbà ẹmi wọn, nwọn kú, nwọn si pada si
erupẹ wọn.
30 Iwọ rán ẹmi rẹ jade, a si da wọn: iwọ
si sọ oju ilẹ di ọtun.
31 Ogo Oluwa yio wà lailai: Oluwa yio
yọ̀ ni iṣẹ ọwọ rẹ̀.
32 O bojuwo aiye, o si warìri: o fi ọwọ
kàn òke, nwọn si ru ẽfin.
33 Emi o ma kọrin si Oluwa nigbati mo
wà lãye: emi o ma kọrin iyìn si Ọlọrun mi
ni igba aiye mi.
34 Jẹ ki iṣaro mi ki o mu inu rẹ̀ dùn:
emi o ma yọ̀ ninu Oluwa.
35 Jẹ ki awọn ẹlẹṣẹ ki o run kuro li aiye,
ki awọn enia buburu ki o má si mọ. Fi
ibukún fun Oluwa, iwọ ọkàn mi. Ẹ fi
iyìn fun Oluwa.

## ORIN 105.

EFI ọpẹ fun Oluwa! ẹ pè orukọ rẹ̀: ẹ fi
iṣẹ rẹ̀ hàn ninu awọn enia.
2 Ẹ kọrin si i, ẹ kọ orin mimọ́ si i: ẹ
ma sọrọ iṣẹ iyanu rẹ̀ gbogbo.
3 Ẹ ma ṣogo li orukọ rẹ̀ mimọ́; jẹ ki
aiya awọn ti nwá Oluwa ki o yọ̀.
4 Ẹ ma wá Oluwa ati ipá rẹ̀: ẹ ma wá
oju rẹ̀ nigbagbogbo.
5 Ẹ ma ranti iṣẹ iyanu rẹ̀ ti o ti ṣe; iṣẹ
àmi rẹ̀ ati idajọ ẹnu rẹ̀;
6 Ẹnyin iru-ọmọ Abrahamu iranṣẹ rẹ̀,
ẹnyin ọmọ Jakobu, ayanfẹ rẹ̀.
7 Oluwa, on li Ọlọrun wa: idajọ rẹ̀ mbẹ
ni gbogbo aiye.
8 O ti ranti majẹmu rẹ̀ lailai, ọ̀rọ ti o ti
pa li aṣẹ fun ẹgbẹrun iran.

Digitized by Google

9 Majẹmu ti o ba Abrahamu dá, ati
ibura rẹ̀ fun Isaaki;
10 O si gbé eyi na kalẹ li ofin fun Jakobu,
ati fun Israeli ni majẹmu aiyeraiye.
11 Pe, iwọ li emi o fi ilẹ Kenaani fun,
ipin ilẹ-ini nyin.
12 Nigbati o ṣe pe kiun ni nwọn wà ni
iye; nitõtọ, diẹ kiun, nwọn si ṣe alejo ninu
rẹ̀.
13 Nigbati nwọn nlọ lati orilẹ-ède de
orilẹ-ède, lati ijọba kan de ọdọ awọn enia
miran;
14 On kò jẹ ki ẹnikẹni ki o ṣe wọn ni
iwọsi: Nitõtọ, o ba awọn ọba wi nitori
wọn;
15 Pe, Ẹ máṣe fi ọwọ kan ẹni-ororo mi
ki ẹ má si ṣe awọn woli mi ni ibi,
16 Pẹlupẹlu o pè ìyan wá si ilẹ na: o ṣẹ́
gbogbo ọpá onjẹ.
17 O rán ọkọnrin kan lọ siwaju wọn;
ani Josefu ti a tà li ẹrú:
18 Ẹsẹ ẹniti nwọn fi ṣẹkẹṣẹkẹ pa lara: a
dè e ninu irin:
19 Titi igba ti ọ̀rọ rẹ̀ de: ọ̀rọ Oluwa dan
a wò.
20 Ọba ranṣẹ, nwọn si tú u silẹ; ani
ijoye awọn enia, o si jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ.
21 O fi jẹ oluwa ile rẹ̀, ati ijoye gbogbo
ini rẹ̀.
22 Lati ma ṣe akoso awọn ọmọ-alade rẹ̀
nipa ifẹ rẹ̀; ati lati ma kọ́ awọn igbimọ rẹ̀
li ọgbọ́n.
23 Israeli si wá si Egipti pẹlu; Jakobu
si ṣe atipo ni ilẹ Hamu.
24 O si mu awọn enia rẹ̀ bi si i pipọ̀-
pipọ̀; o si mu wọn lagbara jù awọn ọta
wọn lọ.
25 O yi wọn li aiya pada lati korira
awọn enia rẹ̀, lati ṣe arekereke si awọn
iranṣẹ rẹ̀.
26 O rán Mose iranṣẹ rẹ̀; ati Aaroni,
ẹniti o ti yàn.
27 Nwọn fi ọ̀rọ àmi rẹ̀ hàn ninu wọn, ati
iṣẹ iyanu ni ilẹ Hamu.
28 O rán òkunkun, o si mu u ṣú; nwọn
kò si ṣaigbọran si ọ̀rọ rẹ̀.
29 O sọ omi wọn di ẹ̀jẹ, o si pa ẹja wọn.
30 Ilẹ wọn mu ọ̀pọlọ jade wá li ọ̀pọlọpọ,
ni iyẹwu awọn ọba wọn.
31 O sọ̀rọ, oniruru ẹṣinṣin si de, ati ina-
aṣọ ni gbogbo agbegbe wọn.
32 O fi yinyin fun wọn fun òjo, ati ọwọ
iná ni ilẹ wọn.
33 O si lu àjara wọn, ati igi ọ̀pọtọ wọn;
o si dá igi àgbegbe wọn.
34 O sọ̀rọ, eṣú si de ati kokoro li ainiye.
35 Nwọn si jẹ gbogbo ewebẹ ilẹ wọn,
nwọn si jẹ eso ilẹ wọn run.
36 O kọlu gbogbo akọbi pẹlu ni ilẹ wọn,
ãyo gbogbo ipa wọn.
37 O si mu wọn jade, ti awọn ti fadaka
ati wura: kò si si alailera kan ninu ẹ̀ya rẹ̀.
38 Inu Egipti dùn nigbati nwọn lọ:
nitoriti ẹ̀ru wọn bà wọn.
39 O nà awọsanma kan fun ibori; ati
iná lati fun wọn ni imọle li oru.
40 Nwọn bère o si mu ẹiyẹ aparo wá, o
si fi onjẹ ọrun tẹ wọn lọrun.
41 O là apata, omi si tú jade; odò nṣan
nibi gbigbẹ,
42 Nitoriti o ranti ileri rẹ̀ mimọ́, ati
Abrahamu iranṣẹ rẹ̀.
43 O si fi ayọ̀ mu awọn enia rẹ̀ jade, ati
awọn ayanfẹ rẹ̀ pẹlu orin ayọ̀:
44 O si fi ilẹ awọn keferi fun wọn: nwọn
si jogun ère iṣẹ awọn enia na.
45 Ki nwọn ki o le ma kiye si aṣẹ rẹ̀, ki
nwọn ki o si ma pa ofin rẹ̀ mọ́. Ẹ fi iyìn
fun Oluwa.

## ORIN 106.

EFI iyìn fun Oluwa! Ẹ fi ọpẹ fun Olu-
wa: nitoriti o ṣeun: nitoriti ti ãnu
rẹ̀ duro lailai.
2 Tali o le sọ̀rọ iṣẹ agbara Oluwa? tali o
le fi gbogbo iyìn rẹ̀ hàn?
3 Ibukún ni fun awọn ti npa idajọ mọ́,
ati ẹniti nṣe ododo ni igbagbogbo.
4 Oluwa, fi oju-rere ti iwọ ni si awọn
enia rẹ ṣe iranti mi: fi igbala rẹ bẹ̀ mi wò.
5 Ki emi ki o le ri ire awọn ayanfẹ rẹ,
ki emi ki o le yọ̀ ninu ayọ̀ orilẹ-ède rẹ, ki
emi ki o le ma ṣogo pẹlu awọn enia ilẹ-ini rẹ.
6 Awa ti ṣẹ̀ pẹlu awọn baba wa, awa
ti dẹṣẹ, awa ti ṣe buburu.
7 Iṣẹ iyanu rẹ kò yé awọn baba wa ni
Egipti; nwọn kò ranti ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ;
ṣugbọn nwọn ṣọ̀tẹ si ọ nibi okun, ani nibi
Okun pupa.
8 Ṣugbọn o gbà wọn là nitori orukọ rẹ̀,
ki o le mu agbara rẹ̀ nla di mimọ̀.
9 O ba Okun pupa wi pẹlu, o si gbẹ:
bẹ̃li o sìn wọn là ibu ja bi aginju.
10 O si gbà wọn là li ọwọ ẹniti o korira
wọn, o si rà wọn pada li ọwọ ọta nì.
11 Omi si bò awọn ọta wọn: ẹnikan
wọn kò si kù.
12 Nigbana ni nwọn gbà ọ̀rọ rẹ̀ gbọ́:
nwọn si kọrin iyìn rẹ̀.
13 Nwọn kò pẹ igbagbe iṣẹ rẹ̀: nwọn
kò si duro de imọ̀ rẹ̀.

Digitized by Google

14 Nwọn si ṣe ifẹkufẹ li aginju, nwọn
si dan Ọlọrun wò ninu aṣálẹ̀.
15 O si fi ifẹ wọn fun wọn; ṣugbọn o
rán rirù si ọkàn wọn.
16 Nwọn ṣe ilara Mose pẹlu ni ibudo,
ati Aaroni, ẹni-mimọ́ Oluwa.
17 Ilẹ là, o si gbé Datani mì, o si bò
ẹgbẹ́ Abiramu mọlẹ.
18 Iná si ràn li ẹgbẹ́ wọn; ọwọ́ iná na
jó awọn enia buburu.
19 Nwọn ṣe ẹgbọrọ malu ni Horebu,
nwọn si foribalẹ fun ere didà.
20 Bayi ni nwọn pa ogo wọn dà si
àworan malu ti njẹ koriko.
21 Nwọn gbagbe Ọlọrun, Olugbala wọn,
ti o ti ṣe ohun nla ni ilẹ Egipti.
22 Iṣẹ iyanu ni ilẹ Hamu, ati ohun ẹ̀ru
lẹba Okun pupa.
23 Nitorina li o ṣe wipe, on o run wọn,
iba máṣe pe Mose, ayanfẹ rẹ̀, duro niwaju
rẹ̀ li oju-ẹya na, lati yi ibinu rẹ̀ pada, ki
o má ba run wọn.
24 Nitõtọ, nwọn kò kà ilẹ didara nì si,
nwọn kò gbà ọ̀rọ rẹ̀ gbọ́:
25 Ṣugbọn nwọn nkùn ninu agọ wọn,
nwọn kò si feti si ohùn Oluwa.
26 Nitorina li o ṣe gbé ọwọ rẹ̀ soke si
wọn, lati bì wọn ṣubu li aginju:
27 Lati bì iru-ọmọ wọn ṣubu pẹlu lãrin
awọn orilẹ-ède, ati lati fún wọn ka kiri ni
ilẹ wọnni.
28 Nwọn da ara wọn pọ̀ pẹlu mọ Baali-
Peoru, nwọn si njẹ ẹbọ okú.
29 Bayi ni nwọn fi iṣẹ wọn mu u binu:
àrun nla si fó si arin wọn.
30 Nigbana ni Finehasi dide duro, o si
ṣe idajọ: bẹ̃li àrun nla na si dá.
31 A si kà eyi na si fun u li ododo lati
irandiran titi lai.
32 Nwọn bi i ninu pẹlu nibi omi Ijà,
bẹ̃li o buru fun Mose nitori wọn:
33 Nitori ti nwọn mu ẹmi rẹ̀ binu, bẹ̃li
o fi ẹnu rẹ̀ sọ ọ̀rọ aiyẹ.
34 Nwọn kò run awọn orilẹ-ède na, niti
ẹniti Oluwa paṣẹ fun wọn:
35 Ṣugbọn nwọn da ara wọn pọ̀ mọ́
awọn keferi, nwọn si kọ́ iṣẹ wọn.
36 Nwọn si sìn ere wọn: ti o di ikẹkun
fun wọn.
37 Nitõtọ nwọn fi ọmọkọnrin wọn ati
ọmọbirin wọn rubọ si oriṣa.
38 Nwọn si ta ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ silẹ, ani ẹ̀jẹ
awọn ọmọkọnrin wọn ati ti awọn ọmọbirin
wọn, ti nwọn fi rubọ si ere Kenaani: ilẹ
na si di aimọ́ fun ẹ̀jẹ.
39 Nwọn si fi iṣẹ ara wọn sọ ara wọn di
alaimọ́, nwọn si ṣe panṣaga lọ pẹlu iṣẹ
wọn.
40 Nitorina ni ibinu Oluwa ṣe ràn si
awọn enia rẹ̀, o si korira awọn enia ini rẹ̀.
41 O si fi wọn le awọn keferi lọwọ;
awọn ti o korira wọn si ṣe olori wọn.
42 Awọn ọta wọn si ni wọn lara, nwọn
si mu wọn sìn labẹ ọwọ wọn.
43 Igba pupọ li o gbà wọn: sibẹ nwọn
fi ìmọ wọn mu u binu, a si rẹ̀ wọn silẹ
nitori ẹ̀ṣẹ wọn.
44 Ṣugbọn ninu ipọnju o kiyesi wọn,
nigbati o gbọ́ ẹkún wọn.
45 O si ranti majẹmu rẹ̀ fun wọn, o si
yi ọkàn pada gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ̀.
46 O si mu wọn ri ãnu loju gbogbo awọn
ti o kó wọn ni igbekun.
47 Oluwa Ọlọrun wa, gbà wa, ki o si
ṣa wa jọ kuro lãrin awọn keferi, lati ma
fi ọpẹ fun orukọ mimọ́ rẹ, ati lati ma ṣogo
ninu iyìn rẹ.
48 Olubukún ni Oluwa, Ọlọrun Israeli,
lati aiyeraiye: ki gbogbo enia ki o si ma
wipe, Amin. Ẹ fi iyìn fun Oluwa.

## ORIN 107.

EFI ọpẹ fun Oluwa, nitori ti o ṣeun:
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
2 Jẹ ki awọn ẹni-irapada Oluwa ki o wi
bẹ̃, ẹniti o rà pada kuro li ọwọ ọta nì.
3 O si kó wọn jọ lati ilẹ wọnnì wá, lati
ila-õrun wá, ati lati ìwọ-õrun, lati ariwa,
ati lati okun wá.
4 Nwọn nrìn ka kiri li aginju ni ibi ti
ọ̀na kò si: nwọn kò ri ilu lati ma gbe.
5 Ebi pa wọn, ongbẹ si gbẹ wọn, o rẹ̀
ọkàn wọn ninu wọn.
6 Nigbana ni nwọn kigbe pè Oluwa
ninu ipọnju wọn, o si yọ wọn kuro ninu
iṣẹ́ wọn,
7 O si mu wọn jade nipa ọ̀na titọ, ki
nwọn ki o le lọ si ilu ti nwọn o ma gbe.
8 Enia iba ma yìn Oluwa nitori ore rẹ̀,
ati nitori iṣẹ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ enia!
9 Nitori ti o tẹ́ ifẹ ọkàn lọrun, o si fi
ire kún ọkàn ti ebi npa.
10 Iru awọn ti o joko li òkunkun ati li
ojiji ikú, ti a dè ninu ipọnju ati ni irin;
11 Nitori ti nwọn ṣọ̀tẹ si ọ̀rọ Ọlọrun,
nwọn sì gàn ìmọ Ọga-ogo:
12 Nitorina o fi lãla rẹ̀ aiya wọn silẹ:
nwọn ṣubu, kò si si oluranlọwọ.
13 Nigbana ni nwọn kigbe pè Oluwa ninu
ipọnju wọn, o si gbà wọn ninu iṣẹ́ wọn.
14 O mu wọn jade kuro ninu òkunkun
ati ojiji ikú, o si fa ìde wọn ja.



Digitized by Google

15 Enia iba ma yìn Oluwa: nitori ore
rẹ̀, ati nitori iṣẹ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ enia.
16 Nitori ti o fọ ilẹkun idẹ wọnni, o si
ke ọpa-idabu irin wọnni li agbedemeji.
17 Aṣiwere nitori irekọja wọn, ati nitori
ẹ̀ṣẹ wọn, oju npọ́n wọn.
18 Ọkàn wọn kọ̀ onjẹ-konjẹ; nwọn si
sunmọ́ eti ẹnu-ọ̀na ikú.
19 Nigbana ni nwọn kigbe pè Oluwa
ninu ipọnju wọn, o si gbà wọn ninu iṣẹ́
wọn.
20 O rán ọ̀rọ rẹ̀, o si mu wọn lara da, o
si gbà wọn kuro ninu iparun wọn.
21 Enia iba ma yìn Oluwa nitori ore rẹ̀,
ati nitori iṣẹ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ enia.
22 Si jẹ ki nwọn ki o ru ẹbọ ọpẹ, ki
nwọn ki o si fi orin ayọ̀ sọ̀rọ iṣẹ rẹ̀.
23 Awọn ti nsọkalẹ lọ si okun ninu ọkọ̀,
ti nwọn nṣiṣẹ ninu omi nla.
24 Awọn wọnyi ri iṣẹ Oluwa, ati iṣẹ-
iyanu rẹ̀ nibu ibú.
25 Nitori ti o paṣẹ, o si mu ìji fẹ, ti o
gbé riru rẹ̀ soke.
26 Nwọn gòke lọ si ọrun, nwọn si tún
sọkalẹ lọ si ibú; ọkàn wọn di omi nitori
ipọnju.
27 Nwọn nta gbọ̀ngbọ́n sihin sọhun,
nwọn ta gbọ̀ngbọ́n bi ọmuti enia, ọgbọ́n
wọn si de opin.
28 Nigbana ni nwọn kigbe pè Oluwa
ninu ipọnju wọn, o si yọ wọn kuro ninu
iṣẹ́ wọn.
29 O sọ ìji di idakẹ-rọrọ́, bẽni riru omi
rẹ̀ duro jẹ.
30 Nigbana ni nwọn yọ̀, nitori ti ara
wọn balẹ; bẽli o mu wọn wá si ebute ifẹ
wọn.
31 Enia iba ma yìn Oluwa nitori ore
rẹ̀, ati nitori iṣẹ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ
enia!
32 Ki nwọn ki o gbé e ga pẹlu ni ijọ
enia, ki nwọn ki o si yìn i ninu ijọ awọn
àgba.
33 O sọ odò di aginju, ati orisun omi di
ilẹ gbigbẹ;
34 Ilẹ eleso di aṣálẹ̀, nitori ìwa-buburu
awọn ti o wà ninu rẹ̀.
35 O sọ aginju di adagun omi, ati ilẹ
gbigbẹ di orisun omi.
36 Nibẹ li o si mu awọn ti ebi npa joko,
ki nwọn ki o le tẹ ilu do, lati ma gbe.
37 Lati fún irugbin si oko, ki nwọn si
gbìn àgbala ajara, ti yio ma so eso ọ̀pọlọpọ.
38 O busi i fun wọn pẹlu, bẽni nwọn
si pọ̀ si i gidigidi; kò si jẹ ki ẹran-ọ̀sin
wọn ki o fà sẹhin.
39 Ẹ̀wẹ nwọn bùku, nwọn si fà sẹhin,
nipa inira, ipọnju, ati ikãnu.
40 O dà ẹ̀gan lù awọn ọmọ-alade, o si
mu wọn rìn kiri ni ijù, nibiti ọ̀na kò si.
41 Sibẹ o gbé talaka ìeke kuro ninu
ipọnju, o si ṣe idile wọnni bi agbo-ẹran.
42 Awọn ẹni diduro-ṣinṣin yio ri i, nwọn
o si yọ̀: gbogbo ẹ̀ṣẹ ni yio si pa ẹnu rẹ̀ mọ.
43 Ẹniti o gbọ́n, yio si kiyesi nkan
wọnyi; awọn na li oye iṣeun-ifẹ Oluwa yio
ma ye.

## ORIN 108.

OLỌRUN, ọkàn mi ti mura, emi o ma
kọrin, emi o si ma fi ogo mi kọrin iyìn.
2 Ji, ohun-elo orin mimọ́ ati dùru: emi
tikarami yio si ji ni kutukutu.
3 Emi o ma yìn ọ, Oluwa, ninu awọn
enia: emi o ma kọrin si ọ ninu awọn orilẹ-
èdè.
4 Nitori ti ãnu rẹ tobi jù ọrun lọ: ati
otitọ rẹ titi de awọsanma.
5 Gbé ara rẹ ga, Ọlọrun, lori awọn ọrun:
ati ogo rẹ lori gbogbo aiye.
6 Ki a le gbà awọn olufẹ rẹ là: fi ọwọ
ọtún rẹ ṣe igbala, ki o si da mi lohùn.
7 Ọlọrun ti sọ ninu ìwa-mimọ́ rẹ̀ pe;
Emi o yọ̀, emi o pin Ṣekemu, emi o si wọ̀n
afonifoji Sukkotu.
8 Ti emi ni Gileadi: ti emi ni Manasse:
Efraimu pẹlu li agbara ori mi: Juda li
olofin mi:
9 Moabu ni ikoko-iwẹsẹ mi; lori Edomu
li emi o bọ́ bata mi si; lori Filistia li emi
o ho iho-ayọ̀.
10 Tani yio mu mi wá sinu ilu olodi ni?
tani yio sìn mi lọ si Edomu?
11 Iwọ Ọlọrun ha kọ́, ẹniti o ti ṣa wa
tì? Ọlọrun, iwọ kì yio si ba awọn ogun
wa jade lọ?
12 Fun wa ni iranlọwọ ninu ipọnju:
nitori asan ni iranlọwọ enia.
13 Nipasẹ Ọlọrun li awa o ṣe aki; nitori
on ni yio tẹ̀ awọn ọta wa mọlẹ.

## ORIN 109.

MÁṢE pa ẹnu rẹ mọ́, Ọlọrun iyìn mi;
2 Nitori ti ẹnu awọn enia buburu,
ati ẹnu awọn ẹlẹtan yà silẹ si mi: nwọn ti
fi ahọn eke sọ̀rọ si mi.
3 Nwọn si fi ọ̀rọ irira yi mi ka kiri;
nwọn si mba mi ja li ainidi.
4 Nipo ifẹ mi nwọn nṣe ọta mi: ṣugbọn
emi ngba adura.
5 Nwọn si fi ibi san ire fun mi, ati irira
fun ifẹ mi.

Digitized by Google

6 Yan enia buburu tì i: jẹ ki Olufisùn ki o duro li ọwọ ọtún rẹ̀.

7 Nigbati a o ṣe idajọ rẹ̀, ki a da a lẹbi: ki adura rẹ̀ ki o di ẹ̀ṣẹ;

8 Ki ọjọ rẹ̀ ki o kuru; ki ẹlomiran ki o rọpo iṣẹ rẹ̀.

9 Ki awọn ọmọ rẹ̀ ki o di alaini-baba, ki aya rẹ̀ ki o di opó.

10 Jẹ ki awọn ọmọ rẹ̀ ki o di alarin-kiri, ti nṣagbe: ki nwọn ki o ma tọrọ onjẹ jina si ibi ahoro wọn.

11 Jẹ ki alọnilọwọ-gbà ki o mu ohun gbogbo ti o ni; ki alejo ki o kó ere-iṣẹ rẹ̀ lọ.

12 Ki ẹnikẹni ki o má si lati ṣãnu fun u: má si ṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o si lati ṣe oju rere fun awọn ọmọ rẹ̀ alaini-baba.

13 Ki a ke ati ọmọ-de-ọmọ rẹ̀ kuro? ati ni iran ti mbọ̀ ki orukọ wọn ki o parẹ.

14 Ki a ma ranti ẹ̀ṣẹ awọn baba rẹ̀ lọdọ Oluwa; má si jẹ ki a nù ẹ̀ṣẹ iya rẹ̀ nù.

15 Jẹ ki nwọn ki o wà niwaju Oluwa nigbagbogbo, ki o le ke iranti wọn kuro lori ilẹ.

16 Nitori ti kò ranti lati ṣãnu, ṣugbọn o ṣe inunibini si ọkọnrin talaka ati olupọnju ni, ki o le pa oniro-binujẹ-ọkàn.

17 Bi o ti fẹ egun, bẹ̃ni ki o de si i: bi inu rẹ̀ kò ti dùn si ire, bẹ̃ni ki o jina si i.

18 Bi o ti fi egun wọ̀ ara rẹ li aṣọ bi ẹwu rẹ̀, bẹ̃ni ki o wá si inu rẹ̀ bi omi, ati bi orõro sinu egungun rẹ̀.

19 Jẹ ki o ri fun u bi aṣọ ti o bò o lara, ati fun àmure ti o fi gbajá nigbagbogbo.

20 Eyi li ère awọn ọta mi lati ọwọ Oluwa wá, ati ti awọn ti nsọ̀rọ ibi si ọkàn mi.

21 Ṣugbọn iwọ ṣe fun mi, Ọlọrun Oluwa, nitori orukọ rẹ: nitoriti ãnu rẹ dara, iwọ gbà mi.

22 Nitoripe talaka ati olupọnju li emi aiya mi si gbọgbẹ ninu mi.

23 Emi nkọja lọ bi ojiji ti o nfà sẹhin, emi ntì soke tì sodò bi eṣú.

24 Ẽkun mi di ailera nitori igbawẹ; ẹran-ara mi si gbẹ nitori ailọra.

25 Emi di ẹ̀gan fun wọn pẹlu: nigbati nwọn wò mi, nwọn mì ori wọn.

26 Ràn mi lọwọ, Oluwa Ọlọrun mi: gbà mi gẹgẹ bi ãnu rẽ.

27 Ki nwọn ki o le mọ̀ pe ọwọ rẹ li eyi; pe Iwọ, Oluwa, li o ṣe e.

28 Nwọn o ma gegun, ṣugbọn iwọ ma sure: nigbati nwọn ba dide, ki oju ki o tì wọn; ṣugbọn iranṣẹ rẹ yio yọ̀.

29 Jẹ ki a fi ìtiju wọ̀ awọn ọta mi li aṣọ, ki nwọn ki o si fi idaru-dapọ̀ wọn bò ara, bi ẹnipe ẹ̀wu.

30 Emi o ma fi ẹnu mi yìn Oluwa gidigidi; nitõtọ, emi o ma yìn i lãrin ọ̀pọ enia.

31 Nitori ti yio duro li ọwọ ọtún olupọnju, lati gbà a lọwọ awọn ti o nda ọkàn rẹ̀ lẹbi.

## ORIN 110.

OLUWA wi fun Oluwa mi pe, Iwọ joko li ọwọ ọtún mi, titi emi o fi sọ awọn ọta rẹ di apoti-itisẹ rẹ.

2 Oluwa yio nà ọpá agbara rẹ lati Sioni wá: iwọ jọba larin awọn ọta rẹ.

3 Awọn enia rẹ yio jẹ ọrẹ atinuwá li ọjọ ijade-ogun rẹ, ninu ẹwà ìwa-mimọ́: lati inu owurọ wá, iwọ ni ìri ewe rẹ.

4 Oluwa ti bura, kì yio si yi ọkàn pada pe, Iwọ li alufa titi lai nipa ẹsẹ ti Melkisedeki.

5 Oluwa li ọwọ ọtún rẹ ni yio lù awọn ọba jalẹ li ọjọ ibinu rẹ̀.

6 Yio ṣe idajọ lãrin awọn keferi, yio fi okú kún ibi wọnni; yio fọ́ ori lori ilẹ pupọ̀.

7 Yio ma mu ninu odò na li ọ̀na: nitorina ni yio ṣe gbé ori soke.

## ORIN 111.

EMA yìn Oluwa. Emi o ma yìn Oluwa tinutinu mi, ninu ijọ awọn ẹni diduroṣinṣin, ati ni ijọ enia.

2 Iṣẹ Oluwa tobi, iwa-kiri ni fun gbogbo awọn ti o ni ifẹ rẹ̀ ninu.

3 Iṣẹ rẹ̀ li ọlá on ogo, ododo rẹ̀ si duro lailai.

4 O ṣe iṣẹ iyanu rẹ̀ ni iranti: olore-ọfẹ li Oluwa o si kún fun ãnu.

5 O ti fi onjẹ fun awọn ti o bẹru rẹ̀: yio ranti majẹmu rẹ̀ lailai.

6 O ti fi iṣẹ agbara rẹ̀ hàn awọn enia rẹ̀, ki o le fun wọn ni ilẹ-ini awọn keferi.

7 Otitọ ati idajọ ni iṣẹ ọwọ rẹ̀; gbogbo ofin rẹ̀ li o daniloju.

8 Nwọn duro lai ati lailai, ninu otitọ ati iduro-ṣinṣin li a ṣe wọn.

9 O rán idande si awọn enia rẹ̀: o ti paṣẹ majẹmu rẹ̀ lailai: mimọ́ ati ọ̀wọ li orukọ rẹ̀.

10 Ìbẹru Oluwa ni ipilẹṣẹ ọgbọ́n: oye rere ni gbogbo awọn ti npa ofin rẹ̀ mọ́ ni: iyìn rẹ̀ duro lailai.

Digitized by Google

## ORIN 112.

EMA yìn Oluwa. Ibukún ni fun ẹniti o bẹ̀ru Oluwa, ti inu rẹ̀ dùn jọjọ li ofin rẹ̀.

2 Iru-ọmọ rẹ̀ yio lagbara li aiye: iran ẹni-diduro-ṣinṣin li a o bukún fun.

3 Ọlà ati ọrọ̀ yio wà ni ile rẹ̀: ododo rẹ̀ si duro lailai.

4 Fun ẹni-diduro-ṣinṣin ni imọlẹ mọ́ li òkunkun: olore-ọfẹ, o si kún fun ãnu, o si ṣe olododo.

5 Enia rere fi oju-rere hàn, a si wínni: imoye ni yio ma fi là ọ̀na iṣẹ rẹ̀.

6 Nitoriti a kì yio yi i nipò pada lailai: olododo yio wà ni iranti titi aiye.

7 Kì yio bẹ̀ru ihin buburu: aiya rẹ̀ ti mu ọ̀na kan, o gbẹkẹle Oluwa.

8 Aiya rẹ̀ ti mulẹ, kì yio bẹ̀ru, titi yio fi ri ifẹ rẹ̀ lori awọn ọta rẹ.

9 O ti fún ka, o ti fi fun awọn olupọnju; ododo rẹ̀ duro lailai; ọlá li a o fi gbé iwo rẹ̀ ga.

10 Awọn enia buburu yio ri i, inu wọn o si bajẹ; yio pa ehin rẹ̀ keke, yio si yọ́ danu: ifẹ awọn enia buburu yio ṣegbe.

## ORIN 113.

EMA yìn Oluwa! Ẹ ma yìn, ẹnyin iranṣẹ Oluwa, ẹ ma yìn orukọ Oluwa.

2 Ibukún li orukọ Oluwa lati isisiyi lọ ati si i lailai.

3 Lati ila-õrun titi o fi de ìwọ rẹ̀ orukọ Oluwa ni ki a yìn.

4 Oluwa ga lori gbogbo orilẹ-ède, ogo rẹ̀ si wà lori ọrun.

5 Tali o dabi Oluwa Ọlọrun wa, ti o ngbe ibi giga.

6 Ẹniti o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ lati wò ohun ti o wà li ọrun ati li aiye!

7 O gbé talaka soke lati inu erupẹ wá, o si gbé olupọnju soke lati ori àtan wá;

8 Ki o le mu u joko pẹlu awọn ọmọ-alade, ani pẹlu awọn ọmọ-alade awọn enia rẹ̀.

9 O mu àgan obirin gbe inu ile, lati ma ṣe oninu-didùn iya awọn ọmọ. Ẹ ma yìn Oluwa.

## ORIN 114.

NIGBATI Israeli jade kuro ni Egipti, ti ara-ile Jakobu kuro ninu àjeji ède enia;

2 Juda ni ibi mimọ́ rẹ̀, Israeli ni ijọba rẹ̀.

3 Okun ri i, o si sá: Jordani pada sẹhin.

4 Awọn òke nla nfò bi àgbo, ati awọn òke kekèke bi ọdọ-agutan.

5 Kili o ṣe ọ, iwọ okun, ti iwọ fi sá? iwọ Jordani ti iwọ fi pada sẹhin?

6 Ẹnyin òke nla, ti ẹ fi nfò bi àgbo; ati ẹnyin òke kekèke bi ọdọ-agutan?

7 Warìri, iwọ ilẹ, niwaju Oluwa, niwaju Ọlọrun Jakobu.

8 Ẹniti o sọ apata di adagun omi, ati okuta-ibọn di orisun omi.

## ORIN 115.

KÌ iṣe fun wa, Oluwa, kì iṣe fun wa, bikoṣe orukọ rẹ li a fi ogo fun nitori ãnu rẹ, ati nitori otitọ rẹ.

2 Nitori kili awọn keferi yio ṣe wipe, Nibo li Ọlọrun wọn wà nisisiyi?

3 Ṣugbọn Ọlọrun wa mbẹ li ọrun: o nṣe ohun-kohun ti o wù u.

4 Fadaka ati wura li ere wọn, iṣẹ ọwọ enia.

5 Nwọn li ẹnu, ṣugbọn nwọn kò sọrọ: nwọn li oju, ṣugbọn nwọn kò riran.

6 Nwọn li eti, ṣugbọn nwọn kò gbọran: nwọn ni imu, ṣugbọn nwọn kò gbõrun.

7 Nwọn li ọwọ, ṣugbọn nwọn kò lò o: nwọn li ẹsẹ, ṣugbọn nwọn kò rìn: bẽni nwọn kò sọrọ lati ọfun wọn jade.

8 Awọn ti nṣe wọn dabi wọn; bẽli olukuluku ẹniti o gbẹkẹle wọn.

9 Israeli, iwọ gbẹkẹle Oluwa: on ni iranlọwọ wọn ati asà wọn.

10 Ara-ile Aaroni, gbẹkẹle Oluwa, on ni iranlọwọ wọn ati asà wọn.

11 Ẹnyin ti o bẹ̀ru Oluwa, gbẹkẹle Oluwa: on ni iranlọwọ wọn ati asà wọn.

12 Oluwa ti nṣe iranti wa: yio bùsi i fun wa: yio bùsi i fun ara-ile Israeli; yio bùsi i fun ara-ile Aaroni.

13 Yio bùsi i fun awọn ti o bẹ̀ru Oluwa, ati ewe ati àgba.

14 Oluwa yio mu nyin bisi i siwaju ati siwaju, ẹnyin ati awọn ọmọ nyin.

15 Ẹnyin li ẹni-ibukún Oluwa, ti o da ọrun on aiye.

16 Ọrun ani ọrun ni ti Oluwa; ṣugbọn aiye li o fi fun awọn ọmọ enia.

17 Okú kò yìn Oluwa, ati gbogbo awọn ti o sọkalẹ lọ sinu idakẹ.

18 Ṣugbọn awa o ma fi ibukún fun Oluwa, lati igba yi lọ ati si i lailai. Ẹ yìn Oluwa.

## ORIN 116.

EMI fẹ Oluwa nitori ti o gbọ́ ohùn mi ati ẹ̀bẹ mi.

Digitized by Google

2 Nitori ti o dẹ eti rẹ̀ si mi, nitorina li
emi o ma kepè e niwọn ọjọ mi.
3 Ikãnu ikú yi mi ka, ati irora isa-okú
di mi mu; mo ri iyọnu ati ikãnu.
4 Nigbana ni mo kepè orukọ Oluwa;
Oluwa, emi bẹ̀ ọ, gbà ọkàn mi.
5 Olore ọfẹ li Oluwa, ati olododo; nitõ-
tọ alãnu li Ọlọrun wa.
6 Oluwa pa awọn alaimọ̀kan mọ́: a rẹ̀
mi silẹ tan, o si ràn mi lọwọ.
7 Pada si ibi isimi rẹ, iwọ ọkàn mi;
nitori ti Oluwa ṣe ọ̀pọlọpọ fun ọ.
8 Nitori ti iwọ gbà ọkàn mi lọwọ ikú,
oju mi lọwọ omije, ati ẹsẹ mi lọwọ iṣubu.
9 Emi o ma rìn niwaju Oluwa ni ilẹ
alãye.
10 Emi gbagbọ́, nitorina li emi ṣe sọ:
mo ri ipọnju gidigidi.
11 Mo wi ni iyara mi pe: Eke ni gbogbo
enia.
12 Kili emi o san fun Oluwa nitori gbo-
gbo ore rẹ̀ si mi?
13 Emi o mu ago igbala, emi o si ma
kepè orukọ Oluwa.
14 Emi o san ileri ifẹ mi fun Oluwa,
nitõtọ li oju gbogbo awọn enia rẹ̀.
15 Iyebiye ni ikú awọn ayanfẹ rẹ̀ li oju
Oluwa.
16 Oluwa nitõtọ iranṣẹ rẹ li emi; iranṣẹ
rẹ li emi, ati ọmọ ìranṣẹ-birin rẹ: iwọ ti
tú ìde mi.
17 Emi o ru ẹbọ ọpẹ si ọ, emi o ma ke
pè orukọ Oluwa.
18 Emi o san ileri ifẹ mi fun Oluwa,
nitõtọ li oju gbogbo awọn enia rẹ̀.
19 Ninu àgbala ile Oluwa, li arin rẹ,
iwọ Jerusalemu. Ẹ yìn Oluwa.

## ORIN 117.

EMA yìn Oluwa, ẹnyin orilẹ-ède gbogbo:
ẹ yìn i, ẹnyin enia gbogbo.
2 Nitoriti iṣeun ãnu rẹ̀ pọ̀ si wa: ati
otitọ Oluwa duro lailai. Ẹ yìn Oluwa!

## ORIN 118.

EFI ọpẹ fun Oluwa; nitoriti o ṣeun, nito-
riti ãnu rẹ̀ duro lailai.
2 Jẹ ki Israeli ki o wi nisisiyi pe, ãnu rẹ̀
duro lailai.
3 Jẹ ki ara-ile Aaroni ki o wi nisisiyi pe,
ãnu rẹ̀ duro lailai.
4 Jẹ ki awọn ti o bẹ̀ru Oluwa ki o wi
nisisiyi pe, ãnu rẹ̀ duro lailai.
5 Mo kepè Oluwa ninu ipọnju: Oluwa
si da mi lohùn ni ibi àye nla.
6 Oluwa mbẹ fun mi, emi kì yio bẹ̀ru;
kili enia le ṣe si mi?
7 Oluwa mbẹ fun mi pẹlu awọn ti nràn
mi lọwọ: nitorina li emi o ṣe ri ifẹ mi lori
awọn ti o korira mi.
8 O ya lati gbẹkẹle Oluwa, jù ati gbẹ-
kẹle enia lọ.
9 O ya lati gbẹkẹle Oluwa, jù ati gbẹkẹle
awọn ọmọ-alade lọ.
10 Gbogbo awọn orilẹ-ède yi mi ka kiri,
ṣugbọn li orukọ Oluwa emi o pa wọn run.
11 Nwọn yi mi ka kiri; nitõtọ, nwọn yi
mi ka kiri, ṣugbọn li orukọ Oluwa emi o
pa wọn run.
12 Nwọn yi mi ka kiri bi oyin; a si pa
wọn bi iná ẹgún: li orukọ Oluwa emi o sa
pa wọn run.
13 Iwọ tì mi gidigidi ki emi ki o le
ṣubu; ṣugbọn Oluwa ràn mi lọwọ.
14 Oluwa li agbara ati orin mi, o si di
igbala mi.
15 Ohùn ayọ̀ ati ti igbala mbẹ ninu agọ
awọn olododo; ọwọ ọtún Oluwa li a gbega:
ọwọ ọtún Oluwa nṣe agbara.
16 Ọwọ ọtún Oluwa li a gbega: ọwọ
ọtún Oluwa nṣe agbara.
17 Emi kì yio kú, bikoṣe yiyè, ki emi ki
o si ma rohin iṣẹ Oluwa.
18 Oluwa nà mi gidigidi: ṣugbọn kò fi
mi fun ikú.
19 Ṣi ilẹkun ẹnu-ọ̀na ododo silẹ fun mi·
emi o ba ibẹ wọle, emi o ma yìn Oluwa.
20 Eyi li ẹnu-ọ̀na Oluwa, ti awọn olodo-
do yio ba wọle.
21 Emi o yìn ọ: nitori ti iwọ gbohùn
mi, iwọ si di igbala mi.
22 Okuta ti awọn ọ̀mọle kọ̀ silẹ li o di
pataki igun ile.
23 Lati ọdọ Oluwa li eyi: o ṣe iyanu li
oju wa.
24 Eyi li ọjọ ti Oluwa da: awa o ma yọ̀,
inu wa yio si ma dùn ninu rẹ̀.
25 Ṣe igbala nisisiyi, emi mbẹ ọ, Oluwa:
Oluwa emi bẹ ọ, rán alafia.
26 Olubukún li ẹniti o mbọ̀ wá li orukọ
Oluwa: awa ti fi ibukún fun ọ lati ile
Oluwa wá.
27 Ọlọrun li Oluwa, ti o ti fi imọlẹ hàn
fun wa: ẹ fi okùn di ẹbọ na mọ́ iwo pẹpẹ
na.
28 Iwọ li Ọlọrun mi, emi o si ma yìn ọ,
iwọ li Ọlọrun mi, emi o ma gbé ọ ga.
29 Ẹ fi ọpẹ fun Oluwa; nitori ti o ṣeun:
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.

Digitized by Google

## ORIN 119.

IBUKÚN ni fun awọn ẹniti o pé li ọ̀na
na, ti nrìn ninu ofin Oluwa.
2 Ibukún ni fun awọn ti npa ẹri rẹ̀ mọ́,
ti si nwá a kiri tinu-tinu gbogbo.
3 Nwọn kò dẹṣẹ pẹlu: nwọn nrìn li ọ̀na
rẹ̀.
4 Iwọ ti paṣẹ fun wa lati pa ẹkọ́ rẹ mọ́
gidigidi.
5 Ọna mi iba jẹ là silẹ lati ma pa ilana
rẹ mọ́!
6 Nigbana li oju kì yio tì mi, nigbati
emi ba njuba aṣẹ rẹ gbogbo.
7 Emi o ma fi aiya diduro-ṣinṣin yìn ọ,
nigbati emi ba ti kọ́ idajọ ododo rẹ.
8 Emi o pa ilana rẹ mọ́: máṣe kọ̀ mi
silẹ patapata.

9 Nipa ewo li ọ̀dọmọkọnrin yio fi mu
ọ̀na rẹ̀ mọ́? nipa ikiyesi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
10 Tinu-tinu mi gbogbo li emi fi ṣe
afẹri rẹ: máṣe jẹ ki emi ṣina kuro ninu
aṣẹ rẹ.
11 Ọ̀rọ rẹ ni mo pamọ́ li aiya mi, ki
emi ki o má ba ṣẹ̀ si ọ.
12 Olubukún ni iwọ, Oluwa: kọ́ mi ni
ilana rẹ.
13 Ẹnu mi li emi fi nsọ gbogbo idajọ
ẹnu rẹ.
14 Emi ti nyọ̀ li ọ̀na ẹri rẹ, bi lori oni-
ruru ọrọ̀.
15 Emi o ma ṣe àṣaro ninu ẹkọ́ rẹ, emi o
si ma juba ọ̀na rẹ.
16 Emi o ma ṣe inu-didùn ninu ilana rẹ:
emi kì yio gbagbe ọ̀rọ rẹ.

17 Fi ọ̀pọlọpọ ba iranṣẹ rẹ ṣe, ki emi ki
o le wà lãye, ki emi ki o le ma pa ọ̀rọ rẹ
mọ́.
18 Là mi li oju, ki emi ki o le ma wò
ohun iyanu wọnni lati inu ofin rẹ.
19 Alejo li emi li aiye: máṣe pa aṣẹ rẹ
mọ́ fun mi.
20 Aiya mi bù nitori ifojusọna si idajọ
rẹ nigbagbogbo.
21 Iwọ ti ba awọn agberaga wi, ti a ti fi
gégun, ti o ti ṣina kuro nipa aṣẹ rẹ.
22 Mu ẹ̀gan ati àbukun kuro lara mi;
nitoriti emi ti pa ẹri rẹ mọ́.
23 Awọn ọmọ-alade joko pẹlu, nwọn
nsọ̀rọ mi: ṣugbọn iranṣẹ rẹ nṣe àṣaro ninu
ilana rẹ:
24 Ẹri rẹ pẹlu ni didùn-inu mi ati ìgbi-
mọ mi.

25 Ọkàn mi lẹ̀ mọ́ erupẹ: iwọ sọ mi di
ãye gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
26 Emi ti rohin ọ̀na mi, iwọ si gbohùn
mi: mã kọ́ mi ni ilana rẹ.
27 Mu oye ọ̀na ẹkọ́ rẹ ye mi: bẹ̃li emi
o ma ṣe aṣaro iṣẹ iyanu rẹ.
28 Ọkàn mi nrọ fun ãrẹ̀: iwọ mu mi
lara le gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
29 Mu ọ̀na eke kuro lọdọ mi: ki o si fi
ore-ọfẹ fi ofin rẹ fun mi.
30 Emi ti yàn ọ̀na otitọ: idajọ rẹ ni mo
fi lelẹ niwaju mi.
31 Emi ti faramọ ẹri rẹ: Oluwa, máṣe
dojutì mi.
32 Emi o ma sare li ọ̀na aṣẹ rẹ, nitori
iwọ bùn aiya mi laye.

33 Oluwa, kọ́ mi li ọ̀na rẹ; emi o si ma
pa a mọ́ de opin.
34 Fun mi li oye, emi o si pa ofin rẹ mọ́;
nitõtọ, emi o ma kiyesi i tinutinu mi
gbogbo.
35 Mu mi rìn ni ipa aṣẹ rẹ; nitori ninu
rẹ̀ ni didùn inu mi.
36 Fa aiya mi si ẹri rẹ, ki o má si ṣe si
oju-kòkoro.
37 Yi oju mi pada kuro lati ma wò ohun
asan; mu mi yè li ọna rẹ.
38 Fi ọ̀rọ rẹ mulẹ si iranṣẹ rẹ, ti iṣe ti
ìbẹru rẹ.
39 Yi ẹ̀gan mi pada ti mo bẹ̀ru: nitori
ti idajọ rẹ dara.
40 Kiyesi i, ọkàn mi ti fà si ẹkọ́ rẹ: sọ
mi di ãye ninu ododo rẹ.

41 Jẹ ki ãnu rẹ ki o tọ̀ mi wá pẹlu,
Oluwa, ani igbala rẹ gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
42 Bẹ̃li emi o ni ọ̀rọ ti emi o fi da ẹni ti
ngàn mi lohùn; nitori mo gbẹkẹle ọ̀rọ rẹ.
43 Lõtọ máṣe gbà ọ̀rọ otitọ kuro li ẹnu
mi rara; nitori ti mo ti nṣe ireti ni idajọ
rẹ.
44 Bẹ̃li emi o ma pa ofin rẹ mọ́ patapata
titi lai ati lailai.
45 Bẹ̃li emi o mã rìn ni alafia; nitori ti
mo wá ẹkọ́ rẹ.
46 Emi o si ma sọ̀rọ ẹri rẹ niwaju awọn
ọba, emi kì yio si tiju.
47 Emi o si ma ṣe inu-didùn ninu aṣẹ rẹ,
ti emi ti fẹ.
48 Ọwọ mi pẹlu li emi o gbe soke si aṣẹ
rẹ, ti emi ti fẹ; emi o si ma ṣe iṣaro ilana
rẹ.

49 Ranti ọ̀rọ nì si ọmọ-ọdọ rẹ lara eyiti
iwọ ti mu mi ṣe ireti.

Digitized by Google

50 Eyi ni itunu mi ninu ipọnju mi:
nitori ọ̀rọ rẹ li o sọ mi di ãye.
51 Awọn agberaga ti nyọ-ṣuti si mi gidi-
gibi: sibẹ emi kò fa sẹhin kuro ninu ofin
rẹ.
52 Oluwa emi ranti idajọ atijọ; emi si
tu ara mi ninu.
53 Mo ni ibinujẹ nla nitori awọn enia
buburu ti o kọ̀ ofin rẹ silẹ.
54 Ilana rẹ li o ti nṣe orin mi ni ile
atipo mi.
55 Emi ti ranti orukọ rẹ Oluwa, li oru,
emi si ti pa ofin rẹ mọ́.
56 Eyi ni mo ni nitori ti mo pa ẹkọ rẹ
mọ́.

57 Oluwa, iwọ ni ipin mi: emi ti wipe,
emi o pa ọ̀rọ rẹ mọ́.
58 Emi ti mbẹ̀bẹ oju-rere rẹ tinutinu mi
gbogbo: ṣãnu fun mi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
59 Emi rò ọ̀na mi, mo si yi ẹsẹ mi pada
si ẹri rẹ.
60 Emi yara, emi kò si lọra lati pa ofin
rẹ mọ́.
61 Okùn awọn enia buburu ti yi mi ka:
ṣugbọn emi kò gbagbe ofin rẹ.
62 Lãrin ọganjọ emi o dide lati dupẹ fun
ọ, nitori ododo idajọ rẹ.
63 Ẹgbẹ gbogbo awọn ti o bẹ̀ru rẹ li emi,
ati ti awọn ti npa ẹkọ́ rẹ mọ́.
64 Oluwa, aiye kún fun ãnu rẹ: kọ́ mi
ni ilana rẹ.

65 Iwọ ti nṣe rere fun iranṣẹ rẹ Oluwa,
gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
66 Kọ́ mi ni ìwa ati ìmọ rere; nitori ti
mo gbà aṣẹ rẹ gbọ́.
67 Ki a to pọ́n mi loju emi ti ṣina:
ṣugbọn nisisiyi emi ti pa ọ̀rọ rẹ mọ́.
68 Iwọ ṣeun iwọ si nṣe rere; kọ́ mi ni
ilana rẹ.
69 Awọn agberaga ti hùmọ eke si mi:
ṣugbọn emi o pa ẹkọ́ rẹ mọ́ tinutinu mi
gbogbo.
70 Aiya wọn sebọ bi ọrá; ṣugbọn emi o
ṣe inu-didùn ninu ofin rẹ.
71 O dara fun mi ti a pọ́n mi loju; ki
emi ki o le kọ́ ilana rẹ.
72 Ofin ẹnu rẹ dara fun mi jù ẹgbẹ-
gbẹrun wura ati fadaka lọ.

73 Ọwọ rẹ li o ti da mi, ti o si ṣe àworan
mi: fun mi li oye, ki emi ki o le kọ́ aṣẹ rẹ.
74 Inu awọn ti o bẹ̀ru rẹ yio dùn, ni-
gbati nwọn ba ri mi; nitori ti mo ti reti
li ọ̀rọ rẹ.

75 Oluwa, emi mọ̀ pe, ododo ni idajọ rẹ,
ati pe li otitọ ni iwọ pọ́n mi loju.
76 Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki iṣeun-ãnu rẹ ki o mã
ṣe itunu mi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ si iranṣẹ rẹ.
77 Jẹ ki ironu ãnu rẹ ki o tọ̀ mi wá, ki
emi ki o le yè: nitori ofin rẹ ni didùn-inu
mi.
78 Jẹ ki oju ki o tì agberaga; nitori ti
nwọn ṣe arekereke si mi li ainidi: ṣugbọn
emi o ma ṣe àṣaro ninu ẹkọ́ rẹ.
79 Jẹ ki awọn ti o bẹ̀ru rẹ ki o yipada si
mi, ati awọn ti o ti mọ̀ ẹri rẹ.
80 Jẹ ki aiya mi ki o pé ni ilana rẹ; ki
oju ki o máṣe tì mi.

81 Ọkàn mi ndaku fun igbala rẹ; ṣu-
gbọn emi ni ireti li ọ̀rọ rẹ.
82 Oju mi ṣofo nitori ọ̀rọ rẹ, wipe, Ni-
gbawo ni iwọ o tù mi ninu?
83 Nitori ti emi dabi igo-awọ loju ẽfin;
ṣugbọn emi kò gbagbe ilana rẹ.
84 Ijọ melo li ọjọ iranṣẹ rẹ? nigbawo ni
iwọ o ṣe idajọ lara awọn ti nṣe inunibini si
mi?
85 Awọn agberaga ti wà ìho silẹ dè mi,
ti kì iṣe gẹgẹ bi ofin rẹ.
86 Otitọ li aṣẹ rẹ gbogbo: nwọn fi are-
kereke ṣe inunibini si mi: iwọ ràn mi lọ-
wọ.
87 Nwọn fẹrẹ run mi li ori ilẹ; ṣugbọn
emi kò kọ̀ ẹkọ́ rẹ silẹ.
88 Sọ mi di ãye gẹgẹ bi iṣeun-ãnu rẹ;
bẽli emi o pa ẹri ẹnu rẹ mọ́.

89 Oluwa, lai, ọ̀rọ rẹ kalẹ li ọrun.
90 Lati iran-diran li otitọ rẹ; iwọ ti fi
idi aiye mulẹ, o si duro.
91 Nwọn duro di oni nipa idajọ rẹ: ni-
tori pe iranṣẹ rẹ ni gbogbo wọn.
92 Bikoṣepe bi ofin rẹ ti ṣe inu-didùn mi,
emi iba ti ṣegbe ninu ipọnju mi.
93 Lai emi kì yio gbagbe ẹkọ́ rẹ; nitori
pe awọn ni iwọ fi sọ mi di ãye.
94 Tirẹ li emi, gbà mi; nitori ti emi wá
ẹkọ́ rẹ.
95 Awọn enia buburu ti duro dè mi lati
pa mi run: ṣugbọn emi o kiyesi ẹri rẹ.
96 Emi ti ri opin ohun pipé gbogbo:
ṣugbọn aṣẹ rẹ gbõro gidigidi.

97 Emi ti fẹ ofin rẹ to! iṣaro mi ni li ọjọ
gbogbo.
98 Nipa aṣẹ rẹ iwọ mu mi gbọ́n jù awọn
ọta mi lọ: nitori ti o wà pẹlu mi lailai.
99 Emi ni iyè ninu jù gbogbo awọn
olukọ mi lọ, nitoripe ẹri rẹ ni iṣaro mi.

Digitized by Google

100 Oye ye mi jù awọn àgba lọ, nitori ti mo pa ẹkọ́ rẹ mọ́.
101 Mo ti fà ẹsẹ mi sẹhin kuro nipa ọ̀na ibi gbogbo, ki emi ki o le pa ọ̀rọ rẹ mọ́.
102 Emi kò yà kuro ni idajọ rẹ; nitoripe iwọ li o kọ́ mi.
103 Ọ̀rọ rẹ ti dùn mọ́ mi li ẹnu to! jù oyin lọ li ẹnu mi!
104 Nipa ẹkọ́ rẹ emi ni iyè ninu: nitorina mo korira ọ̀na eke gbogbo.

105 Ọ̀rọ rẹ ni fitila fun ẹsẹ mi, ati imọlẹ si ipa ọ̀na mi.
106 Emi ti bura, emi o si mu u ṣẹ, pe, emi o pa idajọ ododo rẹ mọ́.
107 A pọ́n mi loju gidigidi: Oluwa sọ mi di ãye, gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
108 Emi bẹ̀ ọ, Oluwa, gbà ọrẹ atinuwa ẹnu mi, ki o si kọ́ mi ni idajọ rẹ.
109 Ọkàn mi wà li ọwọ mi nigbagbogbo: emi kò si gbagbe ofin rẹ.
110 Awọn enia buburu ti dẹkun silẹ fun mi: ṣugbọn emi kò ṣina kuro nipa ẹkọ́ rẹ.
111 Ẹri rẹ ni ogún mi lailai: nitori awọn li ayọ̀ inu mi.
112 Emi ti fà aiya mi si ati pa ilana rẹ mọ́ nigbagbogbo, ani de opin.

113 Emi korira oniye meji: ṣugbọn ofin rẹ ni mo fẹ.
114 Iwọ ni ibi ipamọ́ mi ati asà mi: emi nṣe ireti ninu ọ̀rọ rẹ.
115 Kuro lọdọ mi, ẹnyin oluṣe-buburu: emi o si pa ofin Ọlọrun mi mọ́.
116 Gbé mi soke gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ, ki emi ki o le yè: ki o má si jẹ ki oju ireti mi ki o tì mi.
117 Gbé mi soke, emi o si wà li ailewu: emi o si juba ilana rẹ nigbagbogbo.
118 Iwọ ti tẹ̀ gbogbo awọn ti o ṣina kuro ninu ilana rẹ mọlẹ: nitori pe ẹ̀tan ni ironu wọn.
119 Iwọ ṣá gbogbo awọn enia buburu aiye tì bi ìdarọ́: nitorina emi fẹ ẹri rẹ.
120 Ara mi warìri nitori ìbẹru rẹ; emi si bẹ̀ru idajọ rẹ.

121 Emi ti ṣe idajọ ati ododo: iwọ kì yio jọwọ mi lọwọ fun awọn aninilara mi.
122 Ṣe onigbọwọ fun iranṣẹ rẹ fun rere: máṣe jẹ ki awọn agberaga ki o ni mi lara.
123 Oju kún mi nitori igbala rẹ, ati nitori ọ̀rọ ododo rẹ.
124 Ṣe si iranṣẹ rẹ gẹgẹ bi ãnu rẹ, ki o si kọ́ mi ni ilana rẹ.
125 Iranṣẹ rẹ li emi: fun mi li oye, emi o si mọ̀ ẹri rẹ.
126 Oluwa, o to akokò fun ọ lati ṣiṣẹ: nitori ti nwọn ti sọ ofin rẹ di ofo.
127 Nitorina emi fẹ aṣẹ rẹ jù wura, ani, jù wura didara lọ.
128 Nitorina emi kà gbogbo ẹkọ́ rẹ si otitọ patapata: emi si korira gbogbo ọ̀na eke.

129 Iyanu li ẹri rẹ: nitorina li ọkàn mi ṣe pa wọn mọ́.
130 Ifihan ọ̀rọ rẹ funni ni imọlẹ; o si fi oye fun awọn òpe.
131 Emi yà ẹnu mi, emi mí hẹlẹ: nitori ti ọkàn mi fà si aṣẹ rẹ.
132 Iwọ bojuwò mi; ki o si ṣãnu fun mi, gẹgẹ bi iṣe rẹ si awọn ti o fẹ orukọ rẹ.
133 Fi iṣisẹ mi mulẹ ninu ọ̀rọ rẹ: ki o má si jẹ ki ẹ̀ṣẹkẹṣẹ ki o jọba lori mi.
134 Gbà mi lọwọ inilara enia; bẹ̃li emi o si ma pa ẹkọ́ rẹ mọ́.
135 Ṣe oju rẹ ki o mọlẹ si iranṣẹ rẹ lara; ki o si kọ mi ni ilana rẹ.
136 Odò omi ṣàn silẹ li oju mi nitori nwọn kò pa ofin rẹ mọ́.

137 Olododo ni iwọ, Oluwa, ati diduroṣinṣin ni idajọ rẹ.
138 Iwọ paṣẹ ẹri rẹ li ododo ati otitọ gidigidi.
139 Itara mi ti pa mi run, nitori ti awọn ọta mi ti gbagbe ọ̀rọ rẹ.
140 Funfun gbò li ọ̀rọ rẹ: nitorina ni iranṣẹ rẹ ṣe fẹ ẹ.
141 Emi kere ati ẹni ẹ̀gan ni: ṣugbọn emi kò gbagbe ẹkọ́ rẹ.
142 Ododo rẹ ododo lailai ni, otitọ si li ofin rẹ.
143 Iyọnu ati àrokan dì mi mu: ṣugbọn aṣẹ rẹ ni inu-didùn mi.
144 Ododo ẹri rẹ aiye-raiye ni: fun mi li oye, emi o si yè.

145 Tinu-tinu mi gbogbo ni mo fi kigbe; Oluwa, da mi lohùn; emi o pa ilana rẹ mọ́.
146 Emi kigbe si ọ; gbà mi là, emi o si ma pa ẹri rẹ mọ́.
147 Emi ṣaju kutukutu owurọ, emi ke: emi nṣe ireti ninu ọ̀rọ rẹ.
148 Oju mi ṣaju iṣọ-oru, ki emi ki o le ma ṣe iṣaro ninu ọ̀rọ rẹ.
149 Gbohùn mi gẹgẹ bi ãnu rẹ: Oluwa, sọ mi di ãye gẹgẹ bi idajọ rẹ.
150 Awọn ti nlepa ìwa-ika sunmọ itosi: nwọn jina si ofin rẹ.

151 Oluwa, iwọ wà ni itosi: otitọ si ni
gbogbo aṣẹ rẹ.
152 Lati inu ẹri rẹ, emi ti mọ̀ nigba
atijọ pe, iwọ ti fi idi wọn mulẹ lailai.

153 Wò ipọnju mi, ki o si gbà mi:
nitori ti emi kò gbagbe ofin rẹ.
154 Gbà ẹjọ mi rò, ki o rà mi pada: sọ
mi di ãye nipa ọ̀rọ rẹ.
155 Igbala jina si awọn enia buburu:
nitori ti nwọn kò wá ilana rẹ.
156 Ọ̀pọ ni irọnu ãnu rẹ, Oluwa: sọ mi
di ãye gẹgẹ bi idajọ rẹ.
157 Ọ̀pọ li awọn oninunibini mi ati awọn
ọta mi; ṣugbọn emi kò fà sẹhin kuro ninu
ẹri rẹ.
158 Emi wò awọn ẹlẹtan, inu mi si bajẹ;
nitori ti nwọn kò pa ọ̀rọ rẹ mọ́.
159 Wò bi emi ti fẹ ẹkọ́ rẹ: Oluwa, sọ
mi di ãye gẹgẹ bi ãnu rẹ.
160 Otitọ ni ipilẹṣẹ ọ̀rọ rẹ; ati oluku-
luku idajọ ododo rẹ duro lailai.

161 Awọn ọmọ-alade ṣe inunibini si mi
li ainidi: ṣugbọn ọkàn mi wawìri nitori
ọ̀rọ rẹ.
162 Emi yọ̀ si ọ̀rọ rẹ, bi ẹniti o ri ikogun
pupọ.
163 Emi korira, mo si ṣe hõ si eke ṣiṣe:
ṣugbọn ofin rẹ ni mo fẹ.
164 Nigba meje li õjọ li emi nyìn ọ
nitori ododo idajọ rẹ.
165 Alafia pupọ̀ li awọn ti o fẹ ofin rẹ
ni: kò si si ohun ikọsẹ fun wọn.
166 Oluwa, emi ti nreti igbala rẹ, emi
si ṣe aṣẹ rẹ.
167 Ọkàn mi ti pa ẹri rẹ mọ́; emi si fẹ
wọn gidigidi.
168 Emi ti npa ẹkọ́ ati ẹri rẹ mọ́; nitori
ti gbogbo ọ̀na mi mbẹ niwaju rẹ.

169 Oluwa, jẹ ki ẹkún mi ki o sunmọ
iwaju rẹ: fun mi li oye gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
170 Jẹ ki ẹ̀bẹ mi ki o wá siwaju rẹ: gbà
mi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
171 Ete mi yio sọ iyìn jade, nigbati iwọ
ba ti kọ́ mi ni ilana rẹ.
172 Ahọn mi yio sọ niti ọ̀rọ rẹ: nitori
pe ododo ni gbogbo aṣẹ rẹ.
173 Jẹ ki ọwọ rẹ ki o ràn mi lọwọ;
nitori ti mo ti yàn ẹkọ rẹ.
174 Oluwa, ọkàn mi ti fà si igbala rẹ;
ofin rẹ si ni didùn-inu mi.
175 Jẹ ki ọkàn mi ki o wà lãye, yio si
ma yìn ọ; si jẹ ki idajọ rẹ ki o ma ràn mi
lọwọ.
176 Emi ti ṣina kiri bi agutan ti o nù;
wá iranṣẹ rẹ nitori ti emi kò gbagbe aṣẹ rẹ.

## ORIN 120.

NINU ipọnju mi emi kepè Oluwa, o si
da mi lohùn.
2 Oluwa, gbà ọkàn mi, lọwọ ète eke, ati
lọwọ ahọn ẹ̀tan!
3 Kini ki a fi fun ọ? tabi kini ki a ṣe
si ọ, ahọn ẹ̀tan.
4 Ọfà mimu alagbara, ti on ti ẹyin-iná
igi juniperi!
5 Egbe ni fun mi, ti mo ṣe atipo ni
Meṣeki, ti mo joko ninu agọ Kedari!
6 O ti pẹ ti ọkàn mi ti ba ẹniti o korira
alafia gbe.
7 Alafia ni mo fẹ: ṣugbọn nigbati mo
ba sọ̀rọ, ija ni ti wọn.

## ORIN 121.

EMI o gbè oju mi si ori oke wọnnì, nibo
ni iranlọwọ mi ti nwa?
2 Iranlọwọ mi ti ọwọ Oluwa wá, ti o da
ọrun on aiye.
3 On kì yio jẹ ki ẹsẹ rẹ ki o yẹ̀; ẹniti
npa ọ mọ́ kì yio tõgbe.
4 Kiyesi i, ẹniti npa Israeli mọ́, kì itõ-
gbe, bẽni kì isùn.
5 Oluwa li olupamọ́ rẹ: Oluwa li ojiji
rẹ li ọwọ otún rẹ.
6 Orùn kì yio pa ọ nigba ọsan, tabi
oṣupa nigba oru.
7 Oluwa yio pa ọ mọ́ kuro ninu ibi
gbogbo: yio pa ọkàn rẹ mọ́.
8 Oluwa yio pa alọ ati àbọ rẹ mọ́ lati
igba yi lọ, ati titi lailai.

## ORIN 122.

INU mi dùn nigbati nwọn wi fun mi pe,
Ẹ jẹ ki a lọ si ile Oluwa.
2 Ẹsẹ wa yio duro ni ẹnu-bode rẹ, iwọ
Jerusalemu.
3 Jerusalemu, iwọ ti a kọ́ bi ilu ti o fi
ara mọra pọ̀ ṣọkan.
4 Nibiti awọn ẹ̀ya ima gòke lọ, awọn
ẹ̀ya Oluwa, ẹri fun Israeli, lati ma dupẹ
fun orukọ Oluwa.
5 Nitori ibẹ li a gbé itẹ́ idajọ kalẹ, awọn
itẹ́ ile Dafidi.
6 Gbadura fun alafia Jerusalemu: awọn
ti o fẹ ọ yio ṣe rere.
7 Ki alafia ki o wà ninu odi rẹ, ati ire
ninu ãfin rẹ.
8 Nitori awọn arakọnrin ati awọn ẹgbẹ
mi, emi o wi nisisiyi pe, Ki alafia ki o wà
ninu rẹ!

Digitized by Google

9 Nitori ile Oluwa Ọlọrun wa, emi o ma wá ire rẹ.

## ORIN 123.

IWỌ ni mo gbé oju mi soke si, iwọ ti ngbe inu ọrun.

2 Kiyesi i, bi oju awọn iranṣẹ-kọnrin ti ima wò ọwọ awọn baba wọn, ati bi oju iranṣẹ-birin ti ima wò ọwọ iya rẹ̀; bẹ̃li oju wa nwò Oluwa Ọlọrun wa, titi yio fi ṣãnu fun wa.

3 Oluwa, ṣãnu fun wa, ṣãnu fun wa: nitori ti a kún fun ẹ̀gan pupọ̀-pupọ̀.

4 Ọkàn wa kún pupọ̀-pupọ̀ fun ẹ̀gan awọn onirera, ati fun ẹ̀gan awọn agberaga.

## ORIN 124.

IBA máṣe pe Oluwa ti o ti wà niti wa, ni ki Israeli ki o ma wi nisisiyi;

2 Iba máṣe pe Oluwa ti o ti wà niti wa, nigbati awọn enia duro si wa:

3 Nigbana ni nwọn iba gbé wa mì lãye, nigbati ibinu nwọn ru si wa:

4 Nigbana li omi wọnni iba bò wa mọlẹ, iṣan omi iba ti bori ọkàn wa:

5 Nigbana li agberaga omi iba bori ọkàn wa.

6 Olubukún li Oluwa, ti kò fi wa fun wọn bi ohun ọdẹ fun ehin wọn.

7 Ọkàn wa yọ bi ẹiyẹ jade kuro ninu okùn apẹiyẹ: okùn já, awa si yọ.

8 Iranlọwọ wa mbẹ li orukọ Oluwa, ti o da ọrun on aiye.

## ORIN 125.

AWỌN ti o gbẹkẹle Oluwa yio dabi òke Sioni, ti a kò le ṣi ni idi, bikoṣepe o duro lailai.

2 Bi òke nla ti yi Jerusalemu ka, bẹ̃li Oluwa yi awọn enia rẹ̀ ka lati isisiyi lọ ati titi lailai.

3 Nitori ti ọpá awọn enia buburu kì yio bà le ipin awọn olododo: ki awọn olododo ki o má ba fi ọwọ wọn le ẹ̀ṣẹ.

4 Oluwa ṣe rere fun awọn ẹni-rere, ati fun awọn ti aiya wọn duro ṣinṣin.

5 Bi o ṣe ti iru awọn ti nwọn yà si ipa ọ̀na wiwọ wọn: Oluwa yio jẹ ki wọn lọ pẹlu awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ: ṣugbọn alafia yio wà lori Israeli.

## ORIN 126.

NIGBATI Oluwa mu ikólọ Sioni pada, awa dabi ẹniti nla alá.

2 Nigbana li ẹnu wa kún fun ẹrin, ati ahọn wa kọ orin: nigbana ni nwọn wi ninu awọn keferi pe, Oluwa ṣe ohun nla fun wọn.

3 Oluwa ṣe ohun nla fun wa: nitorina awa nyọ̀.

4 Oluwa mu ikólọ wa pada, bi iṣan-omi ni gusu.

5 Awọn ti nfi omije fún irugbin yio fi ayọ ka.

6 Ẹniti nfi ẹkun rìn lọ, ti o si gbé irugbin lọwọ, lõtọ, yio fi ayọ̀ pada wá, yio si rù iti rẹ̀.

## ORIN 127.

BIKOṢEPE Oluwa ba kọ́ ile na, awọn ti nkọ́ ọ nṣiṣẹ lasan: bikoṣepe Oluwa ba pa ilu mọ́, oluṣọ ji lasan.

2 Asan ni fun ẹnyin ti ẹ dide ni kutukutu lati pẹ iṣiwọ, lati jẹ onjẹ ikãnu: bẹ̃li o nfi ire fun olufẹ rẹ̀ loju orun.

3 Kiyesi i, awọn ọmọ ni ini Oluwa: ọmọ inu si li ère rẹ̀.

4 Bi ọfà ti ri li ọwọ alagbara, bẹ̃li awọn ọmọ ewe.

5 Ibukún ni fun ọkọnrin na ti apó rẹ̀ kún fun wọn: oju kì yio tì wọn, ṣugbọn nwọn ọ ṣẹgun awọn ọta li ẹnu ọ̀na.

## ORIN 128.

IBUKÚN ni fun gbogbo ẹniti o bẹ̀ru Oluwa; ti o si nrìn li ọ̀na rẹ̀.

2 Nitori ti iwọ o jẹ iṣẹ́ ọwọ rẹ: ibukún ni fun ọ: yio si dara fun ọ.

3 Obirin rẹ yio dabi àjara rere eleso pupọ li arin ile rẹ: awọn ọmọ rẹ yio dabi igi olifi yi tabili rẹ ka.

4 Kiyesi i, pe bẹ̃li a o busi i fun ọkọnrin na, ti o bẹ̀ru Oluwa.

5 Ki Oluwa ki o busi i fun ọ lati Sioni wá, ki iwọ ki o si ma ri ire Jerusalemu li ọjọ aiye rẹ gbogbo.

6 Bẹ̃ni ki iwọ ki o si ma ri ati ọmọde-ọmọ rẹ: ati alafia lara Israeli.

## ORIN 129.

IGBA pupọ̀ ni nwọn ti npọ́n mi loju lati igba-ewe mi wá, ni ki Israeli ki o wi nisisiyi.

2 Igba pupọ̀ ni nwọn ti npọ́n mi loju lati igba-ewe mi wá: sibẹ nwọn kò ti ibori mi.

3 Awọn iwalẹ walẹ si ẹhin mi: nwọn si la aporo wọn gigun.

4 Olododo li Oluwa: o ti ke okùn awọn enia buburu kuro.

5 Ki gbogbo awọn ti o korira Sioni ki o dãmu, ki nwọn ki o si yi ẹhin pada.

Digitized by Google

6 Ki nwọn ki o dabi koriko ori-ile ti o
gbẹ danu, ki o to dagba soke:
7 Eyi ti oloko pipa kò kún ọwọ rẹ̀; bẽli
ẹniti ndi ití, kò kún apa rẹ̀.
8 Bẽli awọn ti nkọja lọ kò wipe, Ibukún
Oluwa ki o pẹlu nyin: awa sure fun nyin
li orukọ Oluwa.

## ORIN 130.

LATI inu ibu wá li emi kepe ọ, Oluwa.
2 Oluwa, gbohùn mi, jẹ ki eti rẹ ki o
tẹ́ silẹ si ohùn ẹ̀bẹ mi.
3 Oluwa, ibaṣepe ki iwọ koma sami ẹ̀ṣẹ,
Oluwa, tani iba duro?
4 Nitori idariji wà lọdọ rẹ, ki a le ma
bẹ̀ru rẹ.
5 Emi duro dè Oluwa, ọkàn mi duro,
ati ninu ọ̀rọ rẹ̀ li emi nṣe ireti.
6 Ọkàn mi duro dè Oluwa, jù awọn ti
nṣọ́na owurọ lọ, ani jù awọn ti nṣọ́na owurọ
lọ.
7 Israeli, iwọ ni ireti niti Oluwa: nitori
pe lọdọ Oluwa li ãnu wà, ati lọdọ rẹ̀ li
ọ̀pọlọpọ idande wà.
8 On o si da Israeli nidè kuro ninu ẹ̀ṣẹ
rẹ̀ gbogbo,

## ORIN 131.

OLUWA, aiya mi kò gbega, bẽli oju mi
kò gbé soke: bẽli emi kò fi ọwọ mi le
ọ̀ran nla, tabi le ohun ti o ga jù mi lọ.
2 Nitõtọ emi mu ọkàn mi simi, mo si
mu u dakẹjẹ, bi ọmọ ti a ti ọwọ iya rẹ̀ gbà
li ẹnu-ọmu: ọkàn mi ri gẹ bi ọmọ ti a já li
ẹnu-ọmu.
3 Israeli, iwọ ni ireti niti Oluwa lati
isisiyi lọ ati lailai.

## ORIN 132.

OLUWA, ranti Dafidi ninu gbogbo ipọnju
rẹ̀;
2 Ẹniti o ti bura fun Oluwa, ti o si ṣe
ileri ifẹ fun Alagbara Jakobu pe.
3 Nitõtọ, emi kì yio wọ̀ inu agọ ile mi
lọ, bẽli emi kì yio gùn ori akete mi;
4 Emi kì yio fi orun fun oju mi, tabi
õgbe fun ipenpeju mi,
5 Titi emi o fi ri ibi fun Oluwa, ibujoko
fun Alagbara Jakobu.
6 Kiyesi i, awa gburo rẹ̀ ni Efrata: awa
ri i ninu oko ẹgàn na.
7 Awa o lọ sinu agọ rẹ̀: awa o ma sìn
nibi apoti-itisẹ rẹ̀.
8 Oluwa, dide si ibi isimi rẹ; iwọ, ati
apoti agbara rẹ.
9 Ki a fi ododo wọ̀ awọn alufa rẹ: ki
awọn enia mimọ rẹ ki o ma hó fun ayọ̀.
10 Nitori ti Dafidi iranṣẹ rẹ máṣe yi oju
ẹni-ororo rẹ pada.
11 Oluwa ti bura nitõtọ fun Dafidi; on
kì yio yipada kuro ninu rẹ̀, Ninu iru-ọmọ
inu rẹ li emi o gbé kalẹ si ori itẹ́ rẹ.
12 Bi awọn ọmọ rẹ yio ba pa majẹmu
mi mọ́ ati ẹri mi ti emi o kọ́ wọn, awọn
ọmọ wọn pẹlu yio joko lori itẹ́ rẹ lailai.
13 Nitori ti Oluwa ti yàn Sioni; o ti fẹ
ẹ fun ibujoko rẹ̀.
14 Eyi ni ibi isimi mi lailai: nihin li
emi o ma gbe; nitori ti mo fẹ ẹ.
15 Emi o bukún onjẹ rẹ̀ pupọ̀-pupọ̀:
emi o fi onjẹ tẹ́ awọn talaka rẹ̀ lọrùn.
16 Emi o si fi igbala wọ̀ awọn alufa
rẹ̀: awọn enia mimọ́ rẹ̀ yio ma hó fun ayọ̀.
17 Nibẹ li emi o gbe mu iwo Dafidi yọ,
emi ti ṣe ilana fitila kan fun ẹni-ororo mi.
18 Awọn ọta rẹ̀ li emi o fi itiju wọ̀:
ṣugbọn lara on tikararẹ̀ li ade rẹ̀ yio ma
gbilẹ.

## ORIN 133.

KIYESI I, o ti dara o si ti dùn to fun
awọn ará lati ma jumọ gbe ni irẹpọ̀.
2 O dabi ororo ikunra iyebiye li ori, ti
o ṣàn de irungbọn, ani irungbọn Aaroni: ti
o si ṣàn si eti aṣọ rẹ̀;
3 Bi ìri Hermoni ti o ṣàn sori òke Sioni:
nitori nibẹ ni Oluwa gbe paṣẹ ibukún, ani
ìye lailai.

## ORIN 134.

EKIYESI I, ẹ fi ibukún fun Oluwa,
gbogbo ẹnyin iranṣẹ Oluwa, ti nduro
ni ile Oluwa li oru.
2 Ẹ gbé ọwọ nyin soke si ibi-mimọ́, ki ẹ
si fi ibukún fun Oluwa.
3 Oluwa ti o da ọrun on aiye, ki o busi
i fun ọ lati Sioni wá.

## ORIN 135.

EYÌN Oluwa, Ẹ yìn orukọ Oluwa; ẹ
yìn i, ẹnyin iranṣẹ Oluwa.
2 Ẹnyin ti nduro ni ile Oluwa, ninu
agbalá ile Ọlọrun wa.
3 Ẹ yìn Oluwa: nitori ti Oluwa ṣeun;
ẹ kọrin iyìn si orukọ rẹ̀; ni orin ti o dùn.
4 Nitori ti Oluwa ti yàn Jakobu fun ara
rẹ̀; ani Israeli fun iṣura ãyo rẹ̀.
5 Nitori ti emi mọ̀ pe Oluwa tobi, ati
pe Oluwa jù gbogbo oriṣa lọ.
6 Ohunkohun ti o wù Oluwa, on ni iṣe

Digitized by Google

li ọrun, ati li aiye, li okun, ati ni ọgbun
gbogbo.
7 O mu ikũku gòke lati opin ilẹ wá: o
da manamana fun òjo: o nmu afẹfẹ ti inu
ile iṣura rẹ̀ wá.
8 Ẹniti o kọlù awọn akọbi Egipti, ati ti
enia ati ti ẹranko.
9 Ẹniti o rán àmi ati iṣẹ iyanu si ãrin
rẹ, iwọ Egipti, si ara Farao, ati si ara awọn
iranṣẹ rẹ̀ gbogbo.
10 Ẹniti o kọlu awọn orilẹ-ède pupọ̀, ti
o si pa awọn alagbara ọba.
11 Sihoni, ọba awọn ara Amori, ati Ogu,
ọba Baṣani, ati gbogbo ijọba Kenaani:
12 O si fi ilẹ wọn funni ni ini, ini fun
Israeli, enia rẹ̀.
13 Oluwa, orukọ rẹ duro lailai; iranti
rẹ Oluwa, lati iran-diran.
14 Nitori ti Oluwa yio ṣe idajọ awọn
enia rẹ̀, yio si ṣe iyọ́nu si awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀,
15 Fadaka on wura li ere awọn keferi,
iṣẹ ọwọ enia.
16 Nwọn li ẹnu, ṣugbọn nwọn kò sọ̀rọ;
nwọn li oju, ṣugbọn nwọn kò fi riran.
17 Nwọn li eti, ṣugbọn nwọn kò fi gbọ-
ran; bẹ̃ni kò si ẽmi kan li ẹnu wọn.
18 Awọn ti o ṣe wọn dabi wọn: bẹ̃ si li
olukuluku ẹniti o gbẹkẹle wọn.
19 Ẹnyin arale Israeli, ẹ fi ibukún fun
Oluwa, ẹnyin arale Aaroni, ẹ fi ibukún fun
Oluwa.
20 Ẹnyin arale Lefi, ẹ fi ibukún fun Olu-
wa; ẹnyin ti o bẹ̀ru Oluwa, ẹ fi ibukún fun
Oluwa.
21 Olubukún li Oluwa, lati Sioni wá,
ti ngbe Jerusalemu. Ẹ fi iyìn fun Oluwa.

## ORIN 136.

EFI ọpẹ fun Oluwa: nitoriti o ṣeun;
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
2 Ẹ fi ọpẹ fun Ọlọrun awọn ọlọrun:
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
3 Ẹ fi ọpẹ fun Oluwa awọn oluwa: nito-
ri ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
4 Fun on nikan ti nṣe iṣẹ iyanu nla:
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
5 Fun ẹniti o fi ọgbọ́n da ọrun: nitori
ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
6 Fun ẹniti o tẹ́ ilẹ lori omi: nitori ti
ãnu rẹ̀ duro lailai.
7 Fun ẹniti o dá awọn imọlẹ nla: nitori
ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
8 Õrùn lati jọba ọsan: nitori ti ãnu rẹ̀
duro lailai:
9 Oṣupa ati irawọ lati jọba oru: nitori
ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
10 Fun ẹniti o kọlù Egipti lara awọn
akọbi wọn: nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
11 O si mu Israeli jade kuro lãrin wọn:
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai:
12 Pẹlu ọwọ agbara, ati apa ninà: nitori
ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
13 Fun ẹniti o pin Okun pupa ni ìya:
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai:
14 O si mu Israeli kọja lọ larin rẹ̀: nitó-
ri ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
15 Ṣugbọn o bi Farao ati ogun rẹ̀ ṣubu
ninu Okun pupa: nitori ti ãnu rẹ̀ duro
lailai.
16 Fun ẹniti o sin awọn enia rẹ̀ la aginju
ja: nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
17 Fun ẹniti o kọlù awọn ọba nla:
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
18 O si pa awọn ọba olokiki: nitori ti
ãnu rẹ̀ duro lailai.
19 Sihoni, ọba awọn ara Amori: nitori
ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
20 Ati Ogu, ọba Baṣani: nitori ti ãnu
rẹ̀ duro lailai.
21 O si fi ilẹ wọn funni ni ini, nitori ti
ãnu rẹ̀ duro lailai.
22 Ini fun Israeli, iranṣẹ rẹ̀; nitori ti
ãnu rẹ̀ duro lailai.
23 Ẹniti o ranti wa ni ìwa irẹlẹ wa;
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
24 O si dá wa ni ìde lọwọ awọn ọta wa;
nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
25 Ẹniti o fi onjẹ fun ẹda gbogbo: nitori
ti ãnu rẹ̀ duro lailai;
26 Ẹ fi ọpẹ fun Ọlọrun ọrun; nitori ti
ãnu rẹ̀ duro lailai.

## ORIN 137.

LI ẹba odò Babeli, nibẹ li awa gbe joko,
awa si sọkun nigbati awa ranti Sioni.
2 Awa fi duru wa kọ́ si ori igi willo ti o
wà lãrin rẹ̀.
3 Nitoripe nibẹ li awọn ti o kó wa ni
igbekun bère orin lọwọ wa; ati awọn ti o
ni wa lara bère idaraya wipe; Ẹ kọ orin
Sioni kan fun wa.
4 Awa o ti ṣe kọ orin Oluwa ni ilẹ àjeji!
5 Jerusalemu, bi emi ba gbagbe rẹ, jẹ ki
ọwọ ọtún mi ki o gbagbe ìlò rẹ̀.
6 Bi emi kò ba ranti rẹ, jẹ ki ahọn mi
ki o lẹ̀ mọ èrigi mi; bi emi kò ba fi Jeru-
salemu ṣaju olori ayọ̀ mi gbogbo.
7 Oluwa, ranti ọjọ Jerusalemu lara awọn
ọmọ Edomu, awọn ẹniti nwipe, Wó o palẹ,
wó o palẹ, de ipilẹ rẹ̀!
8 Iwọ, ọmọbirin Babeli, ẹniti a o parun;

Digitized by Google

ibukún ni fun ẹniti o san a fun ọ bi iwọ ti
hù si wa.
9 Ibukún li ẹniti o mu ti o si fi ọmọ
wẹwẹ rẹ ṣán okuta.

## ORIN 138.

EMI o ma yìn ọ tinu-tinu mi gbogbo;
niwaju awọn oriṣa li emi o ma kọrin
iyìn si ọ.
2 Emi ò ma gbadura siha tempili mimọ́
rẹ, emi o si ma yìn orukọ rẹ nitori iṣeun-
ifẹ rẹ ati otitọ rẹ; nitori iwọ gbé ọ̀rọ rẹ ga
jù gbogbo orukọ rẹ lọ.
3 Li ọjọ ti mo kepè, iwọ da mi lohùn,
iwọ si fi ipa mu mi lara le li ọkàn mi.
4 Gbogbo awọn ọba aiye yio yìn ọ, Olu-
wa, nigbati nwọn ba gbọ́ ọ̀rọ ẹnu rẹ.
5 Nitõtọ, nwọn o ma kọrin ni ipa-ọ̀na
Oluwa: nitori pe nla li ogo Oluwa.
6 Bi Oluwa tilẹ ga, sibẹ o juba awọn
onirẹlẹ; ṣugbọn agberaga li o mọ̀ li òkere
rére.
7 Bi emi tilẹ nrìn ninu ipọnju, iwọ ni
yio sọ mi di ãye: iwọ o nà ọwọ rẹ si ibinu
awọn ọta mi, ọwọ ọtún rẹ yio si gbà mi.
8 Oluwa yio ṣe ohun ti iṣe ti emi li
aṣepe: Oluwa, ãnu rẹ duro lailai: máṣe
kọ̀ iṣẹ ọwọ ara rẹ silẹ.

## ORIN 139.

OLUWA, iwọ ti wadi mi, iwọ si ti mọ̀
mi.
2 Iwọ mọ̀ ijoko mi ati idide mi, iwọ mọ̀
ìro mi li ọ̀na jijin rére.
3 Iwọ yi ipa ọ̀na mi ká ati ibulẹ mi,
gbogbo ọ̀na mi si di mimọ̀ fun ọ.
4 Nitori ti kò si ọ̀rọ kan li ahọn mi,
kiyesi i, Oluwa, iwọ mọ̀ ọ patapata.
5 Iwọ sé mi mọ lẹhin ati niwaju, iwọ si
fi ọwọ rẹ le mi.
6 Iru ìmọ yi ṣe ohun iyanu fun mi jù; o
ga, emi kò le mọ̀ ọ.
7 Nibo li emi o gbe lọ kuro lọwọ ẹmi rẹ?
tabi nibo li emi o sárè kuro niwaju rẹ?
8 Bi emi ba gòke lọ si ọrun, iwọ wà
nibẹ: bi emi ba si tẹ́ ẹni mi ni ipò okú,
kiyesi i, iwọ wà nibẹ.
9 Emi iba mu iyẹ-apa owurọ, ki emi si
lọ joko niha opin okun;
10 Ani nibẹ na li ọwọ rẹ yio fà mi, ọwọ
ọtún rẹ yio si dì mi mu.
11 Bi mo ba wipe, Njẹ ki òkunkun ki
o bò mi mọlẹ; ki imọlẹ ki o di oru yi mi
ka.
12 Nitõtọ òkunkun kì iṣu lọdọ rẹ; ṣu-
gbọn oru tàn imọlẹ bi ọsan: ati òkunkun
ati ọsan, mejiji bakanna ni fun ọ.
13 Nitori iwọ li o dá ọkàn mi: iwọ li o
bò mi mọlẹ ni inu iya mi.
14 Emi o yìn ọ; nitori tẹ̀ru-tẹ̀ru ati ti-
yanu-tiyanu li a dá mi: iyanu ni iṣẹ rẹ;
eyinì li ọkàn mi si mọ̀ dajudaju.
15 Ẹda ara mi kò pamọ kuro lọdọ rẹ,
nigbati a da mi ni ìkọkọ, ti a si nṣiṣẹ mi li
àrabara niha isalẹ ilẹ aiye.
16 Oju rẹ ti ri ohun ara mi ti o wà
laipé: ati ninu iwe rẹ li ati kọ gbogbo wọn
si, li ojojumọ li a nda wọn, nigbati ọkan
wọn kò ti isi.
17 Ọlọrun, ìro inu rẹ ti ṣe iye-biye to
fun mi, iye wọn ti pọ̀ to!
18 Emi iba kà wọn, nwọn jù iyanrin lọ
ni iye: nigbati mo ba jí, emi wà lọdọ rẹ
sibẹ.
19 Ọlọrun iba jẹ pa enia buburu nitõtọ:
nitorina kuro lọdọ mi ẹnyin ọkọnrin ẹ̀jẹ.
20 Ẹniti nfi inu buburu sọ̀rọ si ọ, awọn
ọta rẹ npè orukọ rẹ li asan!
21 Oluwa, njẹ emi kò korira awọn ti o
korira rẹ? njẹ inu mi kò ha si bajẹ si
awọn ti o dide si ọ?
22 Emi korira wọn li àkotan: emi kà
wọn si ọta mi.
23 Ọlọrun wadi mi, ki o si mọ̀ aiya mi:
dán mi wò, ki o si mọ̀ ìro-inu mi:
24 Ki o si wò bi ipa-ọ̀na buburu kan ba
wà ninu mi, ki o si fi ẹsẹ mi le ọ̀na ainipẹ-
kun.

## ORIN 140.

OLUWA gbà mi lọwọ ọkọnrin buburu nì,
yọ mi lọwọ ọkọnrin ìka nì;
2 Ẹniti nrò ìwa-buburu ni inu wọn; ni-
gbagbogbo ni nwọn nrú ìja soke si mi.
3 Nwọn ti pọ́n ahọn wọn bi ejo; oro
pãmọlẹ mbẹ li abẹ ète wọn.
4 Oluwa, pa mi mọ́ kuro lọwọ enia bubu-
ru; yọ mi kuro lọwọ ọkọnrin ìka nì; ẹniti
o ti pinnu rẹ̀ lati bì ìrin mi ṣubu.
5 Awọn agberaga ti dẹkùn silẹ fun mi,
ati okùn; nwọn ti nà àwọn lẹba ọ̀na;
nwọn ti kẹkùn silẹ fun mi.
6 Emi wi fun Oluwa pe, iwọ li Ọlọrun
mi: Oluwa, gbọ́ ohùn ẹ̀bẹ mi.
7 Ọlọrun Oluwa, agbara igbala mi, iwọ
li o bò ori mi mọlẹ li ọjọ ìja.
8 Oluwa, máṣe fi ifẹ enia buburu fun u:
máṣe kún ọgbọ́n buburu rẹ̀ lọwọ: ki nwọn
ki o má ba gbé ara wọn ga.
9 Bi o ṣe ti ori awọn ti o yi mi ká kiri
ni, jẹ ki ìka ète ara wọn ki o bò wọn mọlẹ.

Digitized by Google

10 A o da ẹyin iná si wọn lara: on o
wọ́ wọn lọ sinu iná, sinu ọgbun omi jijin,
ki nwọn ki o má le dide mọ́.
11 Máṣe jẹ ki alahọn buburu ki o fi ẹsẹ
mulẹ li aiye: ibi ni yio ma dọdẹ ọkọnrin
ìka nì lati bì i ṣubu.
12 Emi mọ̀ pe, Oluwa yio mu ọ̀ran olu-
pọnju duro, ati are awọn talaka.
13 Nitõtọ awọn olododo yio ma fi ọpẹ
fun orukọ rẹ: awọn ẹni diduro-ṣinṣin yio
ma gbe iwaju rẹ.

## ORIN 141.

OLUWA, emi kigbe pè ọ: yara si ọdọ
mi, fi eti si ohùn mi, nigbati mo ba
nkepè ọ.
2 Je ki adura mi ki o wá si iwaju rẹ bi
ẹbọ turari; ati igbé ọwọ mi soke bi ẹbọ
aṣãlẹ.
3 Oluwa, fi ẹṣọ́ siwaju ẹnu mi; pa ilẹkun
ète mi mọ́.
4 Máṣe fà aiya mi si ohun ibi kan, lati
ma ba awọn ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ ṣiṣẹ buburu; má
si jẹ ki emi ki o jẹ ninu ohun-didùn wọn.
5 Jẹ ki olododo ki o lù mi; iṣeun ni yio
jasi: jẹ ki o si ba mi wi; ororo daradara
ni yio jasi, ti kì yio fọ́ mi lori: sibẹ adura
mi yio sa wà nitori jamba wọn.
6 Nigbati a ba bì awọn onidajọ wọn
ṣubu ni ibi okuta, nwọn o gbọ́ ọ̀rọ mi,
nitori ti o dùn.
7 Egungun wa tàn kalẹ li ẹnu isa-okú, bi
ẹniti o la aporo sori ilẹ.
8 Ṣugbọn oju mi mbẹ lara rẹ; Ọlọrun
Oluwa, lọdọ rẹ ni igbẹkẹle mi wà; máṣe
tú ọkàn mi dà silẹ.
9 Pa mi mọ́ kuro ninu okùn ti nwọn dẹ
silẹ fun mi, ati ikẹkùn awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ.
10 Jẹ ki awọn enia buburu ki o bọ́ sinu
àwọn ara wọn, nigbati emi ba kọja lọ.

## ORIN 142.

*Orin Dafidi; Adura ti o gbà nigbati o wà ninu iho-okuta.*

OLUWA ni mo fi ohùn mi kigbe pè;
ohùn mi ni mo fi mbẹ̀bẹ mi si Oluwa.
2 Emi tú aroye mi silẹ niwaju rẹ̀; emi
fi iṣẹ́ mi hàn niwaju rẹ̀.
3 Nigbati ọkàn mi rẹ̀wẹsi ninu mi, ni-
gbana ni iwọ mọ̀ ipa-ọ̀na mi. Li ọ̀na ti
emi nrìn ni nwọn dẹkùn silẹ fun mi nikọ̀kọ.
4 Emi wò ọwọ ọtún, mo si ri pe, kò si
ẹnikan ti o mọ̀ mi: àbo dẹti fun mi; kò si
ẹniti o nãni ọkàn mi.
5 Oluwa, iwọ ni mo kigbe pè: emi wipe,
iwọ li àbo mi ati ipin mi ni ilẹ alãye.
6 Fiyesi igbe mi: nitori ti a rẹ̀ mi silẹ
gidigidi: gbà mi lọwọ awọn oninunibini
mi.
7 Mu ọkàn mi jade kuro ninu tubu, ki
emi ki o le ma yìn orukọ rẹ; awọn olododo
yio yi mi ka kiri; nitori iwọ o fi ọ̀pọlọpọ ba
mi ṣe.

## ORIN 143.

OLUWA, gbọ́ adura mi, fi eti si ẹ̀bẹ mi;
ninu otitọ rẹ dá mi lohùn ati ninu
ododo rẹ.
2 Ki o má si ba ọmọ-ọdọ rẹ lọ sinu idajọ,
nitori ti kò si ẹniti o wà lãye ti a o dalare
niwaju rẹ.
3 Nitori ti ọta ti ṣe inunibini si ọkàn
mi; o ti lù ẹmi mi bolẹ; o ti mu mi joko
li òkunkun, bi awọn ti o ti kú pẹ.
4 Nitorina li ẹmi mi ṣe rẹ̀wẹsi ninu mi;
òfo fò aiya mi ninu mi.
5 Emi ranti ọjọ atijọ; emi ṣe àṣaro iṣẹ
rẹ gbogbo, emi nronu iṣẹ ọwọ rẹ.
6 Emi nà ọwọ mi si ọ; ongbẹ rẹ ngbẹ
ọkàn mi bi ilẹ gbigbẹ.
7 Oluwa, gbọ́ temi nisisiyi; o rẹ̀ ọkàn
mi tan; máṣe pa oju rẹ mọ́ kuro lara mi,
ki emi ki o má bà dabi awọn ti o lọ sinu
ihò.
8 Mu mi gbọ́ iṣeun-ifẹ rẹ li owurọ; ni-
tori iwọ ni mo gbẹkẹle: mu mi mọ̀ ọ̀na ti
emi iba ma tọ̀; nitori mo gbé ọkàn mi
soke si ọ.
9 Oluwa, gbà mi lọwọ awọn ọta mi: ọdọ
rẹ ni mo sa pamọ́ si.
10 Kọ́ mi lati ṣe ohun ti o wù ọ; nitori
iwọ li Ọlọrun mi: jẹ ki ẹmi rẹ didara fà
mi lọ ni ilẹ ti o tẹju.
11 Oluwa, sọ mi di ãye nitori orukọ rẹ:
ninu ododo rẹ mu ọkàn mi jade ninu iṣẹ́.
12 Ati ninu ãnu rẹ ke awọn ọta mi kuro,
ki o si run gbogbo awọn ti nni ọkàn mi
lara: nitori pe iranṣẹ rẹ li emi iṣe.

## ORIN 144.

OLUBUKÚN li Oluwa apata mi, ẹniti o
kọ́ ọwọ mi li ogun, ati ika mi ni ìja:
2 Ore mi, ati odi-agbara mi; ile-iṣọ giga,
ati olugbala mi; asà mi, ati ẹniti mo gbẹ-
kẹle; eniti o tẹri awọn enia mi ba labẹ mi.
3 Oluwa, kili enia, ti iwọ fi nkiye si i!
tabi ọmọ enia, ti iwọ fi nṣe ìro rẹ̀!
4 Enia dabi asan: bi ojìji ti nkọja lọ li
ọjọ rẹ̀.
5 Oluwa, tẹ̀ ọrun rẹ ba, ki o si sọ̀kalẹ:
tọ́ awọn òke nla, nwọn o si ru ẽfin.

Digitized by Google

6 Kọ manamana jade, ki o si tú wọn ka:
ta ọfà rẹ ki o si dà wọn rún.
7 Rán ọwọ rẹ lati òke wá; yọ mi, ki o
si gbà mi kuro ninu omi nla, li ọwọ awọn
ọmọ àjeji.
8 Ẹnu ẹniti nsọ̀rọ asan, ọwọ ọtún wọn si
jẹ ọwọ ọtún eke.
9 Ọlọrun, emi o kọ orin titun si ọ: lara
ohun ọnà orin olokùn mẹwa li emi o kọrin
iyìn si ọ.
10 On li o nfi igbala fun awọn ọba: ẹniti
o gbà Dafidi iranṣẹ rẹ̀ lọwọ idà pipanilara.
11 Yọ mi, ki o si gbà mi lọwọ awọn ọmọ
àjeji, ẹnu ẹniti nsọ̀rọ asan, ati ọwọ ọtún
wọn jẹ ọwọ ọtún eke:
12 Ki awọn ọmọkọnrin wa, ki o dabi igi
gbigbin ti o dagba ni igba-ewe wọn; ki
awọn ọmọbirin wa ki o le dabi ọwọ̀n igun-
ile, ti a ṣe lọnà bi afarawe ãfin.
13 Ki aká wa ki o le kún, ki o ma funni
li onĩruru iṣura: ki awọn agutan wa ki o
ma bi ẹgbẹgbẹrun ati ẹgbẹgbẹrun mẹwa ni
igboro wa:
14 Ki awọn malu wa ki o le rẹrù; ki o
má si ikọlù, tabi ikolọ jade: ki o má si
aroye ni igboro wa.
15 Ibukún ni fun awọn enia, ti o mbẹ
ni ìru ìwa bẽ: nitõtọ, ibukún ni fun awọn
enia na, ti ẹniti Ọlọrun Oluwa iṣe.

## ORIN 145.

EMI o gbé ọ ga, Ọlọrun mi, ọba mi; emi
o si ma fi ibukún fun orukọ rẹ lai ati
lailai.
2 Li ojojumọ li emi o ma fi ibukún fun
ọ; emi o si ma yìn orukọ rẹ lai ati lailai.
3 Titobi li Oluwa, o si ni iyìn pupọ̀-
pupọ̀; awamaridi si ni titobi rẹ̀.
4 Iran kan yio ma yìn iṣẹ rẹ de ekejĩ,
yio si ma sọ̀rọ iṣẹ agbara rẹ.
5 Emi o sọ̀rọ iyìn ọla-nla rẹ ti o logo,
ati ti iṣẹ iyanu rẹ.
6 Enia o si ma sọ̀rọ agbara iṣẹ rẹ ti o
li ẹ̀ru; emi o si ma ròhin titobi rẹ.
7 Nwọn o ma sọ̀rọ iranti ore rẹ pupọ̀-
pupọ̀, nwọn o si ma kọrin ododo rẹ.
8 Olore-ọfẹ li Oluwa, o kún fun ãnu; o
lọra lati binu, o si li ãnu pupọ̀.
9 Oluwa ṣeun fun ẹni gbogbo; iyọ́nu rẹ̀
si mbẹ lori iṣẹ rẹ̀ gbogbo.
10 Oluwa, gbogbo iṣẹ rẹ ni yio ma yìn
ọ; awọn enia mimọ́ rẹ yio si ma fi ibukún
fun ọ.
11 Nwọn o ma sọ̀rọ ogo ijọba rẹ, nwọn
o si ma sọ̀rọ agbara rẹ:
12 Lati mu iṣẹ agbara rẹ̀ di mimọ̀ fun
awọn ọmọ enia, ati ọla-nla ijọba rẹ̀ ti o logo,
13 Ijọba rẹ ijọba aiye-raiye ni, ati ijọba
rẹ lati iran-diran gbogbo.
14 Oluwa mu gbogbo awọn ti o ṣubu
ró; o si gbe gbogbo awọn ti o tẹriba dide.
15 Oju gbogbo enia nwò ọ; iwọ si fun
wọn li onjẹ wọn li akokò rẹ̀.
16 Iwọ ṣi ọwọ rẹ, iwọ si tẹ́ ifẹ gbogbo
ohun alãye lọrùn.
17 Olododo li Oluwa li ọ̀na rẹ̀ gbogbo,
ati alãnu ni iṣẹ rẹ̀ gbogbo.
18 Oluwa wà leti ọdọ gbogbo awọn ti
nkepè e, leti ọdọ gbogbo ẹniti nkepè e li
otitọ.
19 Yio mu ifẹ awọn ti mbẹ̀ru rẹ̀ ṣẹ: yio
gbọ́ igbe wọn pẹlu, yio si gbà wọn.
20 Oluwa da gbogbo awọn ti o fẹ ẹ si:
ṣugbọn gbogbo enia buburu ni yio parun.
21 Ẹnu mi yio ma sọ̀rọ iyìn Oluwa: ki
gbogbo enia ki o si ma fi ibukún fun orukọ
rẹ̀ mimọ́ lati ati lailai.

## ORIN 146.

EFI iyìn fun Oluwa. Fi iyìn fun Oluwa,
iwọ ọkàn mi.
2 Nigbati mo wà lãye li emi o ma fi iyìn
fun Oluwa: emi o ma kọrin iyìn si Ọlọrun
mi, nigbati mo ni ìwa.
3 Ẹ máṣe gbẹkẹ nyin le awọn ọmọ-alade,
ani le ọmọ-enia, lọwọ ẹniti kò si iranlọwọ.
4 Ẹmi rẹ̀ jade lọ, o pada si erupẹ rẹ̀; li
ọjọ na gan, ìro inu rẹ̀ run.
5 Ibukún ni fun ẹniti o ni Ọlọrun Ja-
kobu fun iranlọwọ rẹ̀, ireti ẹniti mbẹ lọdọ
Oluwa Ọlọrun rẹ̀:
6 Ẹniti o da ọrun on aiye, okun ati ohun
ti o wà ninu wọn: ẹniti o pa otitọ mọ́ titi
aiye:
7 Ẹniti o nṣe idajọ fun ẹnĩ-inilara: ẹniti
o nfi onjẹ fun ẹniti ebi npa. Oluwa tú
awọn aratubu silẹ:
8 Oluwa ṣi oju awọn afọju: Oluwa gbé
awọn ti a tẹ̀ lori ba dide; Oluwa fẹ awọn
olododo:
9 Oluwa pa awọn alejo mọ́; o tù awọn
alainibaba ati opo lara: ṣugbọn ọ̀na awọn
enia buburu ni yio yipò.
10 Oluwa yio jọba lailai, ani Ọlọrun rẹ,
iwọ Sioni, lati iran-diran gbogbo. Ẹ fi
iyìn fun Oluwa.

## ORIN 147.

EFI iyìn fun Oluwa: nitori ohun rere ni
lati ma kọ orin iyìn si Ọlọrun wa:
nitori ti o dùn, iyìn si yẹ.

Digitized by Google

2 Oluwa li o kọ́ Jerusalemu: on li o kó
awọn ifọnkalẹ Israeli jọ.
3 O mu awọn onirora aiya lara da: o di
ọgbẹ wọn:
4 O ka iye awọn ìrawọ; o si pè gbogbo
wọn li orukọ.
5 Oluwa wa tobi, ati alagbara nla: oye
rẹ̀ kò li opin.
6 Oluwa gbé awọn onirẹlẹ soke: o rẹ̀
awọn enia buburu si ilẹyilẹ.
7 Ẹ fi ọpẹ kọrin si Oluwa; kọrin iyìn
si Ọlọrun wa lara duru:
8 Ẹniti o fi awọsanma bò oju ọrun, ẹniti
o pèse òjo fun ilẹ, ti o mu koriko dàgba
lori awọn òke nla.
9 O fi onjẹ ẹranko fun u ati fun ọmọ
ìwò ti ndún.
10 Kò ṣe inudidùn si agbara ẹṣin: kò
ṣe inudidùn si ẹsẹ ọkọnrin.
11 Oluwa nṣe inudidùn si awọn ti o
bẹ̀ru rẹ̀, si awọn ti nṣe ireti ãnu rẹ̀.
12 Yìn Oluwa, iwọ Jerusalemu; yìn
Ọlọrun rẹ, iwọ Sioni.
13 Nitori ti o ti mu ọpá idabu ẹnubode
rẹ le; o ti busi i fun awọn ọmọ rẹ ninu
rẹ.
14 O fi alafia ṣe àgbegbe rẹ, o si fi ali-
kama didara-jù kún ọ.
15 O rán aṣẹ rẹ̀ jade wá si aiye; ọ̀rọ rẹ̀
sure tete.
16 O fi òjo-didì funni bi irun-agutan, o
si fún ìri-didì ká bi ẽru.
17 O dà omi didì rẹ̀ bi òkele; tali o le
duro niwaju otutu rẹ̀.
18 O rán ọ̀rọ rẹ̀ jade, o si mu wọn yọ́;
o mu afẹfẹ rẹ̀ fẹ, omi si nṣàn.
19 O fi ọ̀rọ rẹ̀ hàn fun Jakobu, aṣẹ rẹ̀
ati idajọ rẹ̀ fun Israeli.
20 Kò ba orilẹ-ède kan ṣe bẽ ri; bi o
si ṣe ti idajọ rẹ̀ ni, nwọn kò mọ̀ wọn. Ẹ
fi iyìn fun Oluwa.

## ORIN 148.

Ẹ FI iyìn fun Oluwa, Ẹ fi iyìn fun Oluwa
lati ọrun wá; ẹ fi iyìn fun u ni ibi
giga.
2 Ẹ fi iyìn fun u, gbogbo ẹnyin angeli
rẹ̀; ẹ fi iyìn fun u, gbogbo ẹnyin ọmọ-ogun
rẹ̀.
3 Ẹ fi iyìn fun u, õrun ati oṣupa; ẹ fi
iyìn fun u, gbogbo ẹnyin irawọ imọlẹ.
4 Ẹ fi iyìn fun u, ẹnyin ọrun awọn ọrun,
ati ẹnyin omi ti mbẹ loke ọrun.
5 Jẹ ki nwọn ki o ma yìn orukọ Oluwa;
nitori ti on paṣẹ, a si da wọn.
6 O si fi idi wọn mulẹ lai ati lailai; o si
ti ṣe ilana kan ti kì yio kọja.
7 Ẹ yìn Oluwa lati aiye wá, ẹnyin
erinmi, ati gbogbo ibu-omi;
8 Iná ati yinyin òjo-didì ati ikũku; ìji
mu ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ;
9 Ẹnyin òke nla, ati gbogbo òke ke-
kere; igi eleso, ati gbogbo igi Kedari;
10 Ẹranko, ati gbogbo ẹran-ọ̀sin; ohun
ti nrakò, ati ẹiyẹ́ ti nfò;
11 Awọn ọba aiye, ati gbogbo enia;
ọmọ-alade, ati gbogbo onidajọ aiye;
12 Awọn ọdọmọ-kọnrin ati awọn wun-
dia, awọn arugbo enia ati awọn ọmọde;
13 Ki nwọn ki o ma yìn orukọ Oluwa;
nitori orukọ rẹ̀ nikan li o li ọlá; ogo rẹ̀
bori aiye on ọrun.
14 O si gbé iwo kan soke fun awọn enia
rẹ̀, iyìn fun gbogbo enia mimọ́ rẹ̀; ani
awọn ọmọ Israeli, awọn enia ti o sunmọ
ọdọ rẹ̀. Ẹ fi iyìn fun Oluwa.

## ORIN 149.

Ẹ FI iyìn fun Oluwa. Ẹ kọ orin titun
si Oluwa, ati iyìn rẹ̀ ninu ijọ awọn
enia-mimọ́.
2 Jẹ ki Israeli ki o yọ̀ si ẹniti o dá a;
jẹ ki awọn ọmọ Sioni ki o kún fun ayọ̀ si
Ọba wọn.
3 Jẹ ki nwọn ki o yìn orukọ rẹ̀ ninu ijó:
jẹ ki nwọn ki o fi ìlu ati dùru kọrin iyìn
si i.
4 Nitori ti Oluwa ṣe inudidùn si awọn
enia rẹ̀; yio fi igbala ṣe awọn onirẹlẹ li
ẹwà.
5 Jẹ ki awọn enia mimọ́ ki o kún fun
ayọ̀ ninu ogo; ki nwọn ki o ma kọrin
kikan lori ẹni wọn.
6 Ki iyìn Ọlọrun ki o wà li ẹnu wọn,
ati idà oloju meji li ọwọ wọn;
7 Lati san ẹsan lara awọn keferi, ati
ijiya lara awọn enia.
8 Lati fi ẹwọn dè awọn ọba wọn, ati
lati fi ṣẹkẹṣẹkẹ irin dè awọn ọlọ̀tọ wọn;
9 Lati ṣe idajọ si wọn lara, ti a ti kọwe
rẹ̀, ọlá yi ni gbogbo enia mimọ́ rẹ̀ ni. Ẹ fi
iyìn fun Oluwa.

## ORIN 150.

Ẹ FI iyìn fun Oluwa. Ẹ fi iyìn fun
Ọlọrun ninu ibi mimọ́ rẹ̀; yìn i ninu
ofurufu oju-ọrun agbara rẹ̀.
2 Yìn i nitori iṣẹ agbara rẹ̀: yìn i gẹgẹ
bi titobi nla rẹ̀.

Digitized by Google

3 Fi ohùn ipè yìn i: fi ohun-èlo orin ati
duru yìn i.
4 Fi ìlu ati ijó yìn i: fi ohun ọnà orin
olokùn ati fère yìn i.
5 Ẹ yìn i lara aro olohùn òke: ẹ yìn i
lara aro olohùn goro:
6 Jẹ ki ohun gbogbo ti o li ẹmi ki o yìn
Oluwa. Ẹ fi iyìn fun Oluwa.

# IWE OWE.

## ORI 1.

OWE Solomoni, ọmọ Dafidi, ọba Israeli;
2 Lati mọ̀ ọgbọ́n ati ẹkọ́; lati mọ̀ ọ̀rọ
oye;
3 Lati gbà ẹkọ́ ọgbọ́n, ododo, ati idajọ,
ati aiṣègbe;
4 Lati fi oye fun alaimọ̀kan, lati fun
ọdọmọkọnrin ni ìmọ ati ironu.
5 Ọlọgbọ́n yio gbọ́, yio si ma pọ̀ si i li
ẹkọ́; ati ẹni oye yio gba igbimọ̀ ọgbọ́n:
6 Lati mọ̀ owe, ati ìtumọ; ọ̀rọ ọgbọ́n,
ati ọ̀rọ ikọkọ wọn.
7 Ibẹ̀ru Oluwa ni ipilẹṣẹ ìmọ; ṣugbọn
awọn aṣiwere gàn ọgbọ́n ati ẹkọ́.
8 Ọmọ mi, gbọ́ ẹkọ́ baba rẹ, ki iwọ ki o
má si kọ̀ ofin iya rẹ silẹ:
9 Nitoripe awọn ni yio ṣe ade ẹwà fun
ori rẹ, ati ọṣọ́ yi ọrùn rẹ ka.
10 Ọmọ mi, bi awọn ẹlẹṣẹ̀ ba tàn ọ, iwọ
má ṣe gbà.
11 Bi nwọn wipe, Wá pẹlu wa, jẹ ki a
ba fun ẹ̀jẹ, jẹ ki a lugọ ni ikọkọ de alaiṣẹ̀
lainidi.
12 Jẹ ki a gbe wọn mì lãye bi isà-okú;
ati awọn ẹni-diduroṣinṣin bi awọn ti nlọ
sinu iho:
13 Awa o ri onirũru ọrọ̀ iyebiye, awa o
fi ikogun kún ile wa:
14 Dà ipin rẹ pọ̀ mọ arin wa; jẹ ki gbo-
gbo wa ki a jọ ni àpo kan:
15 Ọmọ mi, máṣe rìn li ọ̀na pẹlu wọn:
fà ẹsẹ rẹ sẹhin kuro ni ipa-ọ̀na wọn.
16 Nitori ti ẹsẹ wọn sure si ibi, nwọn si
yara lati ta ẹ̀jẹ silẹ.
17 Nitõtọ, lasan li a nà àwọn silẹ li oju
ẹiyẹkẹiyẹ.
18 Awọn wọnyi si ba fun ẹ̀jẹ ara wọn;
nwọn lumọ nikọkọ fun ẹmi ara wọn.
19 Bẹ̃ni ọ̀na gbogbo awọn ti nṣe ojuko-
koro ère; ti ngba ẹmi awọn oluwa ohun
na.
20 Ọgbọ́n nkigbe lode; o nfọhùn rẹ̀ ni
igboro:
21 O nke ni ibi pataki apejọ, ni gbangba
ẹnubode ilu, o sọ ọ̀rọ rẹ̀ wipe,
22 Yio ti pẹ tó, ẹnyin alaimọ̀kan ti
ẹnyin o fi ma fẹ aimọ̀kan? ati ti awọn ẹlẹ-
gàn yio fi ma ṣe inudidùn ninu ẹ̀gan wọn,
ati ti awọn aṣiwere yio fi ma korira ìmọ?
23 Ẹ yipada ni ibawi mi; kiyesi i, emi
o dà ẹmi mi sinu nyin, emi o fi ọ̀rọ mi hàn
fun nyin.
24 Nitori ti emi pè, ti ẹnyin si kọ̀; ti
emi nà ọwọ mi, ti ẹnikan kò si kà a si:
25 Ṣugbọn ẹnyin ti ṣá gbogbo ìgbimọ mi
tì, ẹnyin kó si fẹ ibawi mi:
26 Emi pẹlu o rẹrin idãmu nyin; emi o
ṣe ẹ̀fẹ nigbati ibẹ̀ru nyin ba de;
27 Nigbati ibẹ̀ru nyin ba de bi ìji, ati
idãmu nyin bi afẹyika-ìji; nigbati wahala
ati àrodun ba de si nyin.
28 Nigbana ni ẹnyin o kepè mi, ṣugbọn
emi kì yio dahùn; nwọn o ṣafẹri mi ni
kùtukùtu, ṣugbọn nwọn kì yio ri mi:
29 Nitori ti nwọn korira ìmọ, nwọn kò
si yàn ibẹ̀ru Oluwa.
30 Nwọn kò fẹ ìgbimọ mi: nwọn gàn
gbogbo ibawi mi.
31 Nitorina ni nwọn o ṣe ma jẹ ninu ère
ìwa ara wọn, nwọn o si kún fun ìmọkimọ
wọn.
32 Nitoripe irọra awọn alaimọ̀kan ni yio
pa wọn, ati alafia awọn aṣiwere ni yio pa
wọn run.
33 Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba fetisi mi yio
ma gbe lailewu, yio si farabalẹ kuro ninu
ibẹ̀ru ibi.

## ORI 2.

ỌMỌ mi, bi iwọ ba fẹ igba ọ̀rọ mi, ki iwọ
si pa ofin mi mọ́ pẹlu rẹ.
2 Ti iwọ dẹti rẹ silẹ si ọgbọ́n, ti iwọ si fi
ọkàn si oye:

Digitized by Google

3 Ani bi iwọ ba nke tọ̀ ìmọ lẹhin, ti iwọ
si gbé ohùn rẹ soke fun oye ;
4 Bi iwọ ba ṣafẹri rẹ̀ bi fadaka, ti iwọ si
nwá a kiri bi iṣura ti a pamọ́ ;
5 Nigbana ni iwọ o mọ̀ ibẹ̀ru Oluwa,
iwọ o si ri ìmọ Ọlọrun.
6 Nitori Oluwa ni ifi ọgbọ́n funni: lati
ẹnu rẹ̀ jade ni ìmọ ati oye ti iwá.
7 O to igbala jọ fun awọn olododo : on
li asà fun awọn ti nrìn dede.
8 O pa ipa-ọ̀na idajọ mọ́, o si pa ọ̀na
awọn ayanfẹ rẹ̀ mọ́.
9 Nigbana ni iwọ o mọ̀ ododo, ati idajọ,
ati aiṣegbe ; ani, gbogbo ipa-ọ̀na rere,
10 Nigbati ọgbọ́n bá wọ̀ inu rẹ lọ, ti ìmọ
si dùn mọ ọkàn rẹ ;
11 Imoye yio pa ọ mọ́, oye yio si ma ṣọ́
ọ :
12 Lati gbà ọ li ọwọ ẹni-ibi, li ọwọ
ọkọnrin ti nsọrọ ayidayida ;
13 Ẹniti o fi ipa-ọ̀na iduroṣinṣin silẹ, lati
rìn li ọ̀na òkunkun ;
14 Ẹniti o yọ̀ ni buburu iṣe, ti o ṣe inu-
didùn si ayidàyidà awọn enia buburu ;
15 Ọ̀na ẹniti o wọ́, nwọn si ṣe arekereke
ni ipa-ọ̀na wọn :
16 Lati gbà ọ li ọwọ ajeji obirin, ani li
ọwọ ajeji obirin ti nfi ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ pọnni ;
17 Ẹniti o kọ̀ ọrẹ́ igbà-ewe rẹ̀ silẹ, ti o si
gbagbe majẹmu Ọlọrun rẹ̀.
18 Nitoripe ile rẹ̀ tẹ̀ sinu ikú, ati ipa-
ọ̀na rẹ̀ sọdọ awọn okú.
19 Kò si ẹniti o tọ̀ ọ lọ ti o si tun pada
sẹhin, bẽni nwọn kì idé ipa-ọ̀na ìye.
20 Ki iwọ ki o le ma rin li ọ̀na enia rere,
ki iwọ ki o si pa ọ̀na awọn olododo mọ́.
21 Nitoripe ẹni-iduroṣinṣin ni yio joko
ni ilẹ na, awọn ti o pé yio si ma wà ninu
rẹ̀.
22 Ṣugbọn awọn enia buburu li a o ke
kuro ni ilẹ aiye, ati awọn olurekọja li a o
si fàtu kuro ninu rẹ̀.

## ORI 3.

ỌMỌ mi, máṣe gbagbe ofin mi ; si jẹ ki
aiya rẹ ki o pa ofin mi mọ́.
2 Nitori ọjọ gigùn, ati ẹmi gigùn, ati
alafia ni nwọn o fi kún u fun ọ.
3 Máṣe jẹ ki ãnu ati otitọ ki o fi ọ silẹ :
so wọn mọ ọrùn rẹ ; kọ wọn si walã aiya
rẹ :
4 Bẽni iwọ o ri ojurere, ati ọ̀na rere loju
Ọlọrun ati enia.
5 Fi gbogbo aiya rẹ gbẹkẹle Oluwa ; ma
si ṣe tẹ̀ si ìmọ ara rẹ.
6 Mọ̀ ọ ni gbogbo ọ̀na rẹ : on o si ma tọ́
ipa-ọna rẹ.
7 Máṣe ọlọgbọ́n li oju ara rẹ ; bẹ̀ru Olu-
wa, ki o si kuro ninu ibi.
8 On o ṣe ilera si idodo rẹ, ati itura si
egungun rẹ.
9 Fi ohun-ini rẹ bọ̀wọ fun Oluwa, ati
lati inu gbogbo akọbi ibisi-oko rẹ :
10 Bẽni aká rẹ yio kún fun ọ̀pọlọ́pọ, ati
agbá rẹ yio si kún fun ọti-waini titun.
11 Ọmọ mi, máṣe kọ̀ ibawi Oluwa ; bẽ-
ni ki agara itọ́ni rẹ̀ ki o máṣe dá ọ :
12 Nitoripe ẹniti Oluwa fẹ on ni itọ́,
gẹgẹ bi baba ti itọ́ ọmọ ti inu rẹ̀ dùn si.
13 Ibukún ni fun ọkọnrin na ti o wá
ọgbọ́n ri, ati ọkọnrin na ti o gbà oye.
14 Nitori ti òwo rẹ̀ ju òwo fadaka lọ, èrè
rẹ̀ si jù ti wura daradara lọ.
15 O ṣe iyebiye jù iyùn lọ : ati ohun
gbogbo ti iwọ le fẹ, kò si eyi ti a le fi we e.
16 Ọjọ gigùn mbẹ li ọwọ ọtún rẹ̀ ; ati li
ọwọ osì rẹ̀, ọrọ̀ ati ọlá.
17 Ọ̀na rẹ̀, ọ̀na didùn ni, ati gbogbo ipa-
ọ̀na rẹ̀, alafia.
18 Igi ìye ni iṣe fun gbogbo awọn ti o dì
i mu : ibukún si ni fun ẹniti o dì i mu
ṣinṣin.
19 Ọgbọ́n li Oluwa fi fi idi aiye sọlẹ, oye
li o si fi pese awọn ọrun.
20 Nipa ìmọ rẹ̀ ni ibú ya soke, ti awọ-
sanma si nsẹ̀ ìri rẹ̀ silẹ.
21 Ọmọ mi, máṣe jẹ ki nwọn ki o lọ
kuro li oju rẹ : pa ọgbọ́n ti o yè, ati imoye
mọ́ :
22 Bẽni nwọn o ma jẹ ìye si ọkàn rẹ, ati
ore-ọfẹ si ọrùn rẹ.
23 Nigbana ni iwọ o ma rìn ọ̀na rẹ laile-
wu, ẹsẹ rẹ kì yio si kọ.
24 Nigbati iwọ dubulẹ, iwọ kì yio bẹ̀ru :
nitõtọ, iwọ o dubulẹ, orun rẹ yio si dùn.
25 Máṣe fòya ẹ̀ru ojijì, tabi idahoro
awọn enia buburu, nigbati o de.
26 Nitori Oluwa ni yio ṣe igbẹkẹle rẹ,
yio si pa ẹsẹ rẹ mọ́ kuro ninu atimu.
27 Máṣe fawọ ire sẹhin kuro lọdọ ẹniti
iṣe tirẹ̀, bi o ba wà li agbara ọwọ rẹ lati
ṣe e.
28 Máṣe wi fun ẹnikeji rẹ pe, Lọ, ki o si
pada wá, bi o ba si di ọla, emi o fi fun ọ ;
nigbati iwọ ni i li ọwọ rẹ.
29 Máṣe gbìro buburu si ọmọnikejì rẹ,
bi on ti joko laibẹ̀ru lẹba ọdọ rẹ.
30 Máṣe ba enia jà lainidi, bi on kò ba
ṣe ọ ni ibi.
31 Máṣe ilara aninilara, má si ṣe yàn
ọkan ninu gbogbo ọ̀na rẹ̀.

Digitized by Google

32 Nitoripe irira li ẹlẹgan loju Oluwa;
ṣugbọn aṣiri rẹ̀ wà pẹlu awọn olododo.
33 Egún Oluwa mbẹ ni ile awọn enia
buburu: ṣugbọn o bukún ibujoko awọn
olõtọ.
34 Nitõtọ o ṣe ẹ̀ya si awọn ẹlẹya: ṣu-
gbọn o fi ore-ọfẹ fun awọn onirẹlẹ.
35 Awọn ọlọgbọ́n ni yio jogun ogo: ṣu-
gbọn awọn aṣiwere ni yio ru itiju wọn.

## ORI 4.

ENYIN ọmọ, ẹ gbọ́ ẹkọ́ baba, ki ẹ si
fiyesi ati mọ̀ oye.
2 Nitori ti mo fun nyin li ẹkọ rere, ẹ
máṣe kọ̀ ofin mi silẹ.
3 Nitoripe ọmọ baba mi li emi iṣe, ẹni-
ikẹ́ ati olufẹ li oju iya mi.
4 On si kọ́ mi pẹlu, o si wi fun mi pe,
jẹ ki aiya rẹ ki o gbà ọ̀rọ mi duro: pa ofin
mi mọ́ ki iwọ ki o si yè.
5 Ni ọgbọ́n, ni oye: máṣe gbagbe; bẹ̃ni
ki iwọ ki o máṣe fà sẹhin kuro li ọ̀rọ ẹnu
mi.
6 Máṣe kọ̀ ọ silẹ, yio si mu ọ tọ́: fẹ ẹ,
yio si pa ọ mọ́.
7 Ipilẹṣẹ ọgbọ́n ni lati ni ọgbọ́n: ati
pẹlu ini rẹ gbogbọ, ni oye.
8 Gbé e ga, on o si ma gbé ọ leke: on o
mu ọ wá si ọlá, nigbati iwọ ba gbá a mọra.
9 On o fi ohun-ọṣọ́ daradara si ọ li ori:
on o fi ọjá daradara fun ori rẹ.
10 Gbọ́, iwọ ọmọ mi, ki o si gbà ọ̀rọ mi;
ọdun ẹmi rẹ yio si di pipọ.
11 Emi ti kọ́ ọ li ọ̀na ọgbọ́n; emi ti mu
ọ tọ̀ ipa-ọ̀na titọ.
12 Nigbati iwọ nrìn, ọ̀na rẹ kì yio há
fun àye; nigbati iwọ nsare, iwọ kì yio fi
ẹsẹ kọ.
13 Di ẹkọ́ mu ṣinṣin, máṣe jẹ ki o lọ; pa
a mọ́, nitori on li ẹmi rẹ.
14 Máṣe bọ si ipa-ọ̀na enia buburu, má
si ṣe rìn li ọ̀na awọn enia ibi.
15 Yẹ̀ ẹ silẹ, máṣe kọja ninu rẹ̀, yẹ̀ kuro
nibẹ, si ma ba tirẹ lọ.
16 Nitoriti nwọn kì isùn bikoṣepe nwọn
hùwa buburu; orun wọn a si dá, bikoṣepe
nwọn ba mu enia ṣubu.
17 Nitori ti nwọn njẹ onjẹ ìwa-ika, nwọn
si nmu ọti-waini ìwa-agbara.
18 Ṣugbọn ipa-ọ̀na awọn olõtọ dabi titàn
imọlẹ, ti o ntàn siwaju ati siwaju titi di
ọsangangan.
19 Ọna awọn enia buburu dabi òkunkun:
nwọn kò mọ̀ ohun ti nwọn ndugbolu.
20 Ọmọ mi, fetisi ọ̀rọ mi; dẹti rẹ silẹ si
ọ̀rọ mi.
21 Máṣe jẹ ki nwọn ki o lọ kuro li oju
rẹ; pa wọn mọ́ li ãrin aiya rẹ.
22 Nitori ìye ni nwọn iṣe fun awọn ti o
wá wọn ri, ati imularada si gbogbo ẹran-ara
wọn.
23 Jù gbogbo ohun ipamọ́, pa aiya rẹ
mọ́; nitoripe lati inu rẹ̀ wá ni orisun ìye.
24 Mu arekereke kuro lọdọ rẹ, ati ète
ẹ̀tan jina rére kuro lọdọ rẹ.
25 Jẹ ki oju rẹ ki o ma wò ọkankan gan,
ki ipenpeju rẹ ki o ma wò gan niwaju rẹ.
26 Ronu ipa-ọ̀na rẹ, gbogbo ọ̀na rẹ ni yio
si fi idi mulẹ.
27 Máṣe yà si apa ọtun tabi si apa òsi, ṣi
ẹsẹ rẹ kuro ninu ibi.

## ORI 5.

ỌMỌ mi, fiyesi ọgbọ́n mi, ki o si dẹti rẹ
si oye mi.
2 Lati ma pa ironu mọ́, ati ki ète rẹ ki
o le ma pa ìmọ mọ́.
3 Nitori ti ète awọn ajeji obirin a ma
kán bi oyin, ẹnu rẹ̀ si kunna jù ororo lọ:
4 Ṣugbọn igbẹhin rẹ̀ koro bi idápa, o si
mú bi idà olojumeji.
5 Ẹsẹ rẹ̀ nsọkalẹ lọ sinu ikú, ìrin-ẹsẹ rẹ̀
de ipo-okú.
6 Ki iwọ má ba ja ipa-ọ̀na ìye, ipa-ọ̀na
rẹ̀ a ma yi sihin yi sọhun, on kò si mọ̀.
7 Njẹ gbọ́ temi nisisiyi, ẹnyin ọmọ, ki
ẹnyin ki o máṣe yà kuro li ọ̀rọ ẹnu mi.
8 Takete kuro lọdọ rẹ̀, má si ṣe sunmọ
eti ilẹkun ile rẹ̀:
9 Ki iwọ ki o má ba fi ọlá rẹ fun ẹlo-
miran, ati ọdun rẹ fun ẹni-ìka;
10 Ki a má ba fi ọrọ̀ rẹ kún ajeji enia;
ki ère-iṣẹ ọwọ rẹ ki o má ba wà ni ile alejo.
11 Iwọ a si ma kãnu ni ikẹhin rẹ̀, ni-
gbati ẹran-ara ati ara rẹ ba parun.
12 Iwọ a si wipe, emi ha ti korira ẹkọ́
to, ti aiya mi si gàn ìbawi:
13 Ti emi kò gbà ohùn awọn olukọ́ mi
gbọ́, tabi ki emi dẹti mi silẹ si awọn ti nkọ́
mi.
14 Emi fẹrẹ wà ninu ibi patapata larin
awujọ, ati ni ijọ.
15 Mu omi lati inu kudu rẹ, ati omi ti
nṣàn lati inu kanga rẹ.
16 Jẹ ki isun rẹ ki o ṣàn kakiri, ati awọn
odò omi ni ita.
17 Ki nwọn ki o jẹ kiki tirẹ, ki o má ṣe
ti awọn ajeji pẹlu rẹ.
18 Jẹ ki orisun rẹ ki o ni ibukun: ki
iwọ ki o si ma yọ̀ tiwọ ti aya igba-ewe rẹ.
19 Bi abo agbọnrin daradara ati abo
galà, jẹ ki ọmu rẹ̀ ki o ma fi ayọ̀ kún ọ

Digitized by Google

nigbagbogbo ; ki o si ma yọ̀ gidigidi ninu
ifẹ rẹ̀ nigbakugba.
20 Ọmọ mi, ẽṣe ti iwọ o fi ma yọ̀ ninu
ifẹ ajeji obirin, ti iwọ o fi gbá aiya ajeji
obirin mọra ?
21 Nitoripe ọ̀na enia mbẹ niwaju Oluwa,
o si nṣiwọ̀n irin wọn gbogbo.
22 Ẹṣẹ ẹni-buburu ni yio mu ontikararẹ̀,
okùn ẹ̀ṣẹ ara rẹ̀ yio si dì i mu.
23 Yio kú li aigbà ẹkọ́, ati ninu ọ̀pọlọpọ
were rẹ̀ yio si ma ṣina kiri.

## ORI 6.

ỌMỌ mi, bi iwọ ba ṣe onigbọwọ fun ọrẹ́
rẹ, bi iwọ ba ṣe ináwọ fun ajeji enia.
2 Bi a ba fi ọ̀rọ ẹnu rẹ dẹkùn fun ọ, bi a
ba fi ọ̀rọ ẹnu rẹ mu ọ.
3 Njẹ, sa ṣe eyi, ọmọ mi, ki o si gbà ara
rẹ silẹ nigbati iwọ ba bọ si ọwọ ọrẹ́ rẹ ; lọ,
rẹ ara rẹ silẹ, ki iwọ ki o si tù ọrẹ́ rẹ.
4 Máṣe fi orun fun oju rẹ, tabi õgbe fun
ipenpeju rẹ.
5 Gbà ara rẹ bi abo agbọnrin li ọwọ ọdẹ,
ati bi ẹiyẹ li ọwọ apẹiyẹ.
6 Tọ ẽrùn lọ, iwọ ọlẹ : kiyesi iṣe rẹ̀ ki
iwọ ki o si gbọ́n :
7 Ti kò ni onidajọ, alabojuto, tabi ala-
koso.
8 Ti npese onjẹ rẹ̀ ni igba-ẹ̀run, ti o si
nkó onjẹ rẹ̀ jọ ni ìgba ikore.
9 Ọlẹ, iwọ o ti sùn pẹ to ? nigbawo ni
iwọ o dide kuro ninu orun rẹ ?
10 Orun diẹ si i, õgbe diẹ si i, ikawọkò-
pọ lati sùn diẹ :
11 Bẹ̃ni òṣi rẹ yio de bi ẹniti nrìn àjo,
ati aini rẹ bi ọkọnrin ti o hamọra ogun.
12 Enia-kenia, ọkọnrin buburu, ti o nrìn
ti on ti ẹnu arekereke,
13 O nṣẹju rẹ̀, o nfi ẹsẹ rẹ̀ sọ̀rọ, o nfi ika
rẹ̀ ṣe ajuwe ;
14 Arekereke mbẹ li aiya rẹ̀, o humọ
ìwa-ika nigbagbogbo ; o ndá ija silẹ.
15 Nitorina ni ipọnju rẹ̀ yio de si i
lojiji ; ojiji ni yio ṣẹ́ laini atunṣe.
16 Ohun mẹfa li Oluwa korira : nitõtọ,
meje li o ṣe irira fun ọkàn rẹ̀ :
17 Oju igberaga, ète eke, ati ọwọ ti nta
ẹ̀jẹ alaiṣẹ silẹ,
18 Aiya ti nhumọ buburu, ẹsẹ ti o yara
ni ire sisa si ìwa-ika,
19 Ẹlẹri eke ti nsọ eke jade, ati ẹniti
ndá ìja silẹ larin awọn arakọnrin.
20 Ọmọ mi, pa aṣẹ baba rẹ mọ́, ki iwọ
ki o má si ṣe kọ̀ ofin iya rẹ silẹ :
21 Dì wọn mọ aiya rẹ nigbagbogbo, ki
iwọ ki o si so o mọ ọrùn rẹ.
22 Nigbati iwọ ba nrìn, yio ma ṣe amọ̀-
na rẹ ; nigbati iwọ ba sùn, yio ma ṣọ ọ ;
nigbati iwọ ba si ji, yio si ma ba ọ sọ̀rọ.
23 Nitoripe aṣẹ ni fitila ; ofin si ni
imọlẹ ; ati ibawi ẹkọ́ li ọ̀na ìye :
24 Lati pa ọ mọ́ kuro lọwọ obirin buburu
nì, lọwọ ahọn ìpọnni ajeji obirin.
25 Máṣe ifẹkufẹ li aiya rẹ si ẹwà rẹ̀ ;
bẹ̃ni ki o má si ṣe jẹ ki on ki o fi ipenpeju
rẹ̀ mu ọ.
26 Nitoripe nipasẹ agbere obirin li enia
fi idi onìṣù-akara kan : ṣugbọn aya enia a
ma wá ìye rẹ̀ daradara.
27 Ọkọnrin le gbé iná li aiya rẹ̀ ki aṣọ
rẹ̀ ki o má jona ?
28 Ẹnikan ha le gun ori ẹyin-iná gbi-
gbona, ki ẹsẹ rẹ̀ ki o má jona ?
29 Bẹ̃li ẹniti o wọle tọ obirin ẹnikeji rẹ̀
lọ ; ẹnikẹni ti o fi ọwọ bà a, kì yio wà li
ailẹṣẹ̀.
30 Nwọn kì igàn ole, bi o ba ṣe pe, o
jale lati tẹ́ ọkàn rẹ̀ lọrùn, nigbati ebi npa
a ;
31 Ṣugbọn bi a ba mu u, yio san a pada
niwọ̀n meje ; gbogbo ini ile rẹ̀ ni yio fi san
ẹsan.
32 Ṣugbọn ẹni ti o ba ba obirin ṣe pan-
ṣaga, oye kù fun u : ẹniti o ba ṣe e yio pa
ẹmi ara rẹ run.
33 Ọgbẹ ati àbukun ni yio ni ; ẹ̀gan rẹ̀
kì yio si nù kuro.
34 Nitori owú ni ibinu ọkọnrin : nito-
rina kì yio dasi li ọjọ ẹsan.
35 On kì yio nani owo idande, bẹ̃ni inu
rẹ̀ kì yio tẹ́, bi iwọ tilẹ sọ ẹ̀bun di pipọ.

## ORI 7.

ỌMỌ mi, pa ọ̀rọ mi mọ́, ki o si fi ofin mi
ṣura pẹlu rẹ.
2 Pa ofin mi mọ́, ki iwọ ki o si yè ; ati
aṣẹ mi bi ọmọloju rẹ.
3 Dì wọn mọ ika rẹ, kọ wọn si wala aiya
rẹ.
4 Wi fun ọgbọ́n pe, Iwọ li arabirin mi ;
ki o si pe oye ni ibatan rẹ obirin :
5 Ki nwọn ki o le pa ọ mọ́ kuro lọwọ
obirin ẹlomiran, lọwọ ajeji ti nfi ọ̀rọ rẹ̀ ṣe
ipọnni.
6 Li oju ferese ile mi li emi sa bojuwò
lãrin ferese mi.
7 Mo si ri ninu awọn ọ̀pe, mo kiyesi
ninu awọn ọmọkọnrin, ọmọkọnrin kan ti
oye kù fun,
8 O nkọja lọ ni igboro li eti igun ile rẹ̀ ;
o si lọ si ọ̀na ile rẹ̀,

Digitized by Google

9 Ni wiriwiri imọlẹ, li aṣālẹ, li oru dudu
ati òkunkun :
10 Si kiyesi i, obirin kan pade rẹ̀, o wọ
aṣọ panṣaga, alarekereke aiya.
11 (O jẹ alariwo ati agidi ; ẹsẹ rẹ̀ kì iduro
ni ile rẹ̀.
12 Nisisiyi o jade, nisisiyi o wà ni
igboro, o si mba ni ibi igun ile gbogbo.)
13 Bẹ̃li o dì i mu, o si fẹnu kò o li ẹnu,
o si fi ọdáju wi fun u pe,
14 Ọrẹ́, alafia mbẹ lọwọ mi, loni ni mo
ti san ẹjẹ́ mi.
15 Nitorina ni mo ṣe jade wá pade rẹ,
lati ṣe afẹri oju rẹ, emi si ri ọ.
16 Emi ti fi aṣọ titẹ ọlọnà tẹ́ akete mi,
ọlọnà finfin ati aṣọ ọ̀gbọ daradara ti Egipti.
17 Emi ti fi turari olõrùn didùn ti mirra,
aloe, ati kinnamoni si akete mi.
18 Wá, jẹ ki a gbà ẹkún ifẹ wa titi yio fi
di owurọ, jẹ ki a fi ifẹ tù ara wa lara.
19 Nitoripe bãle kò si ni ile, o re àjo
ọ̀na jijin :
20 O mu àsuwọn owo kan lọwọ rẹ̀, yio si
de li oṣupa arànmọju.
21 Ọ̀rọ rẹ̀ daradara li o fi mu u fẹ, ipọnni
ète rẹ̀ li o fi ṣẹ́ ẹ li apa.
22 On si tọ̀ ọ lọ lẹsẹkanna bi malu ti
nlọ si ibupa, tabi bi aṣiwere ti nlọ si ibi
ọgbọ́n ìfabà kọ́.
23 Titi ọfà fi gún u li ẹ̀dọ̀ ; bi ẹiyẹ ti
nyara bọ sinu okùn, ti kò si mọ̀ pe fun
ẹmi on ni.
24 Njẹ nisisiyi, ẹnyin ọmọ, ẹ feti si temi,
ki ẹ si fiye si ọ̀rọ ẹnu mi.
25 Máṣe jẹ ki aiya rẹ ki o tẹ̀ si ọ̀na rẹ̀,
máṣe ṣina lọ si ipa-ọ̀na rẹ̀.
26 Nitori ọ̀pọlọpọ enia li o ṣá lulẹ ; ni-
tõtọ ọ̀pọlọpọ alagbara enia li a ti ọwọ rẹ̀
pa.
27 Ile rẹ̀ li ọ̀na ọrun-apadi, ti nsọkalẹ lọ
si iyẹwu ikú.

## ORI 8.

ỌGBỌ́N kò ha nkigbe bi ? Oye kò ha
gbé ohùn rẹ̀ soke bi ?
2 O duro li ori ibi-giga wọnni, lẹba ọ̀na,
nibi ipa-ọ̀na wọnni.
3 O nke li ẹnu-ọ̀na, ati ni ibode ilu, li
atiwọ̀ oju ilẹkun.
4 Ẹnyin enia li emi npè ; ohùn mi si
nkọ si awọn ọmọ enia.
5 Ẹnyin òpe, ẹ mọ̀ ọgbọ́n : ati ẹnyin
aṣiwere ki ẹnyin ki o ṣe alaiya oye.
6 Ẹ gbọ́, nitori ti emi o sọ̀rọ ohun ti o
dara, ati ṣiṣi ète mi yio sọ̀rọ ohun titọ.
7 Nitori ti ẹnu mi yio sọ̀rọ otitọ ; ìwa-
buburu si ni irira fun ète mi.
8 Ninu ododo ni gbogbo ọ̀rọ ẹnu mi ; kò
si ẹ̀tan kan tabi arekereke ninu wọn.
9 Gbangba ni gbogbo wọn jasi fun ẹniti
o yé, o si tọ́ fun awọn ti o nwá ìmọ ri.
10 Gbà ẹkọ mi, kì si iṣe fadaka ; si gbà
ìmọ jù wura àṣayan lọ.
11 Nitori ti ìmọ jù iyùn lọ ; ohun gbo-
gbo ti a le fẹ, kò si eyi ti a le fi we e.
12 Emi ọgbọ́n li o mba imoye gbe, emi
ìmọ si ri imoye ironu.
13 Ibẹ̀ru Oluwa ni ikorira ibi : irera,
ati igberaga, ati ọ̀na ibi, ati ẹnu arekereke,
ni mo korira.
14 Temi ni ìmọ ati ọgbọ́n ti o yè : emi
li oye, emi li agbara.
15 Nipasẹ mi li ọba nṣe akoso, ti awọn
olori si nlàna otitọ.
16 Nipasẹ mi li awọn ijoye nṣolori, ati
awọn ọ̀lọtọ̀, ani gbogbo awọn onidajọ aiye.
17 Mo fẹ awọn ti o fẹ mi ; awọn ti o si
wá mi ni kutukutu yio ri mi.
18 Ọrọ̀ ati ọlá mbẹ lọwọ mi, ani ọrọ̀
daradara ati ododo.
19 Ere mi ta wura yọ ; nitõtọ, jù wura
daradara lọ : ati ọrọ̀ mi jù fadaka àṣayan
lọ.
20 Emi nrìn li ọ̀na ododo, larin ipa-ọ̀na
idajọ :
21 Ki emi ki o le mu awọn ti o fẹ mi
jogun ohun-ini mi, emi o si fi kún iṣura
wọn.
22 Oluwa pèse mi ni ipilẹṣẹ ìwa rẹ̀, ṣaju
iṣẹ rẹ̀ atijọ.
23 A ti yàn mi lati aiyeraiye, lati ipilẹṣẹ,
tabi ki aiye ki o to wà.
24 Nigbati ọgbun kò si, a ti bi mi ; ni-
gbati kò si orisun ti o kún fun omi pipọ.
25 Ki a to fi idi awọn òke-nla sọlẹ, ṣãju
awọn òke li a ti bi mi :
26 Nigbati kò ti ida aiye, tabi pẹ̀tẹlẹ,
tabi ori erupẹ aiye.
27 Nigbati o nṣe ipilẹ awọn ọrun, emi
wà nibẹ : nigbati o fi oṣuwọn ayika le oju
ọgbun.
28 Nigbati o sọ awọsanma lọjọ̀ soke :
nigbati o fi agbara fun orisun ibu :
29 Nigbati o fi aṣẹ rẹ̀ fun okun, ki omi
rẹ̀ ki o máṣe kọja ẹnu rẹ̀ : ati ofin rẹ̀ fun
ipilẹ aiye.
30 Nigbana, emi wà lọdọ rẹ̀, bi oniṣẹ :
emi si jẹ didùn-inu rẹ̀ lojojumọ, emi nyọ̀
nigbagbogbo niwaju rẹ̀ ;
31 Emi nyọ̀ ni ibi-itẹdo aiye rẹ̀ : didùn-
inu mi si wà sipa awọn ọmọ enia.

Digitized by Google

32 Njẹ nisisiyi, ẹ fetisi temi, ẹnyin ọmọ: nitoripe ibukún ni fun awọn ti o tẹle ọ̀na mi:
33 Gbọ́ ẹkọ́, ki ẹnyin ki o si gbọ́n, má si ṣe jẹ ki o lọ.
34 Ibukùn ni fun ẹniti o gbọ́ temi, ti o nṣọ́ ẹnu-ọ̀na mi lojojumọ, ti o si nduro ti opó ẹnu-ilẹkun mi.
35 Nitoripe ẹniti o ri mi, o ri ìye, yio si ri ojurere Oluwa.
36 Ṣugbọn ẹniti o ṣẹ̀ mi, o ṣe ọkàn ara rẹ̀ nikà: gbogbo awọn ti o korira mi, nwọn fẹ ikú.

## ORI 9.

OGBỌ́N ti kọ́ ile rẹ̀, o si gbẹ́ ọwọ̀n rẹ̀ meje:
2 O ti pa ẹran rẹ̀; o ti ṣe àdalu ọti-waini rẹ̀; o si ti tẹ́ tabili rẹ̀.
3 O ti ran awọn ọmọbirin rẹ̀ jade, o nke lori ibi giga ilu, pe,
4 Ẹnikẹni ti o ṣe òpe ki o yà si ihin: fun ẹniti oye kù fun, o wipe,
5 Wá, jẹ ninu onjẹ mi, ki o si mu ninu ọti-waini mi ti mo dàlu.
6 Kọ̀ iwere silẹ ki o si yè; ki o si ma rìn li ọ̀na oye.
7 Ẹniti o ba ba ẹlẹgàn wi, yio gba itiju fun ara rẹ̀, ati ẹniti o ba ba enia buburu wi yio gbà àbukun rẹ̀.
8 Máṣe ba ẹlẹgàn wi, ki o má ba korira rẹ, ba ọlọgbọ́n enia wi, yio si ma fẹ ọ.
9 Fi ẹkọ́ fun ọlọgbọ́n enia, yio si ma gbọ́n siwaju, kọ́ enia olõtọ, yio si ma fẹ ọ.
10 Ibẹ̀ru Oluwa ni ipilẹṣẹ ọgbọ́n: ati ìmọ Ẹni-Mimọ́ li oye.
11 Nitori nipasẹ mi li ọjọ rẹ yio ma lé si i, ati ọdun ìye rẹ yio si ma lé si i.
12 Bi iwọ ba gbọ́n, iwọ o gbọ́n fun ara rẹ: ṣugbọn bi iwọ ba iṣe ẹlẹgàn, iwọ nikan ni yio rù u.
13 Alaroye li aṣiwere obirin: òpe ni kò si mọ̀ nkan.
14 O sa joko li ẹnu-ọ̀na ile rẹ̀, lori apoti, ni ibi giga ilu.
15 Lati ma pè awọn ti nkọja nibẹ, ti nrìn ọ̀na ganran wọn lọ: pe,
16 Ẹnikẹni ti o ba ṣe òpe, ki o yà si ìhin: ẹniti oye kù fun, o wi fun u pe,
17 Omi ole dùn, ati onjẹ ikọkọ si ṣe didùn.
18 Ṣugbọn on kò mọ̀ pe awọn okú wà nibẹ: ati pe awọn alapejẹ rẹ̀ wà ni isalẹ ọrun-apadi.

## ORI 10.

OWE Solomoni ni wọnyi. Ọlọgbọ́n ọmọ ṣe inu-didùn baba rẹ̀, ṣugbọn aṣiwere ọmọ ni ibanujẹ iya rẹ̀.
2 Iṣura ìwa-buburu kò li ère: ṣugbọn ododo ni igbani kuro lọwọ ikú.
3 Oluwa kì yio jẹ ki ebi ki o pa ọkàn olododo; ṣugbọn o yi ifẹ awọn enia buburu danu.
4 Ẹniti o ba dẹ̀ ọwọ a di talaka; ṣugbọn ọwọ awọn alãpọn ni imu ọlà wá.
5 Ẹniti o ba kojọ ni igba-ẹ̀run li ọlọgbọ́n ọmọ: ṣugbọn ẹniti o ba nsùn ni igba ikore li ọmọ ti idoju tì ni.
6 Ibukún wà li ori olododo: ṣugbọn ìwa-agbara ni yio bo ẹnu enia buburu.
7 Ibukún ni iranti olõtọ: ṣugbọn orukọ enia buburu yio rà.
8 Ọlọgbọ́n inu ni yio gbà ofin: ṣugbọn ete werewere li a o parun.
9 Ẹniti o nrìn dede, o rìn dajudaju: ṣugbọn ẹniti o ba nṣe ayida ọ̀na rẹ̀, on li a o mọ̀.
10 Ẹniti nṣẹ́ oju o mu ibanujẹ wá: ṣugbọn ète werewere li a o parun.
11 Kanga ìye li ẹnu olododo: ṣugbọn ìwa-agbara ni yio bo ẹnu enia buburu.
12 Irira ni irú ìja soke: ṣugbọn ifẹ bò gbogbo ẹ̀ṣẹ mọlẹ.
13 Li ète ẹniti o moye li a ri ọgbọ́n: ṣugbọn kùmọ ni fun ẹhin ẹniti oye kù fun.
14 Awọn ọlọgbọ́n a ma to ìmọ jọ: ṣugbọn ẹnu awọn aṣiwere sunmọ iparun.
15 Ọrọ̀ ọlọ̀là ni ilu agbara rẹ̀: aini awọn talaka ni iparun wọn.
16 Iṣẹ olododo tẹ̀ si ìye; èro awọn enia buburu si ẹ̀ṣẹ.
17 Ẹniti o ba pa ẹkọ́ mọ́, o wà ni ipaọ̀na ìye; ṣugbọn ẹniti o ba kọ̀ ibawi o ṣìna.
18 Ẹniti o ba pa ikorira mọ́ li ète eke, ati ẹniti o ba ngba dulumọ, aṣiwere ni.
19 Ninu ọ̀rọ pipọ, a kò le ifẹ ẹ̀ṣẹ kù: ṣugbọn ẹniti o fi ète mọ ète li o gbọ́n.
20 Ahọn olõtọ dabi ãyo fadaka: aiya enia buburu kò ni iye lori.
21 Ete olododo mbọ́ ọ̀pọlọpọ enia: ṣugbọn awọn aṣiwere yio kú li ailọgbọ́n.
22 Ibukún Oluwa ni imu ni ilà, kì isi ifi lãla pẹlu rẹ̀.
23 Bi ẹrín ni fun aṣiwere lati hu ìwaika: ṣugbọn ọlọgbọ́n li ẹni oye.
24 Ibẹ̀ru enia buburu mbọwá ba a: ṣugbọn ifẹ olododo li a o fi fun u.
25 Bi ìji ti ijà rekọja: bẹ̃li enia buburu

Digitized by Google

kì yio si mọ: ṣugbọn olododo ni ipilẹ ainipẹkun.
26 Bi ọti kikan si ehin, ati bi ẽfin si oju, bẽli ọlẹ si ẹniti o rán a ni iṣẹ.
27 Ibẹ̀ru Oluwa mu ọjọ gùn: ṣugbọn ọdun enia buburu li a o ṣẹ́ kuru.
28 Abá olododo ayọ̀ ni yio jasi: ṣugbọn ireti enia buburu ni yio ṣegbe.
29 Ọ̀na Oluwa ilu olodi ni fun ẹni iduroṣinṣin, ṣugbọn egbe ni fun awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ.
30 A kì yio ṣi olododo ni ipo lai; ṣugbọn enia buburu kì yio gbe ilẹ-aiye.
31 Ẹnu olõtọ mu ọgbọ́n jade; ṣugbọn ahọn arekereke li a o ke kuro.
32 Ete olododo mọ̀ ohun itẹwọgba; ṣugbọn ẹnu enia buburu nsọ̀rọ arekereke.

## ORI 11.

OṢUWỌN eke irira ni loju Oluwa; ṣugbọn òṣuwọn otitọ ni didùn inu rẹ̀.
2 Bi igberaga ba de, nigbana ni itiju de, ṣugbọn ọgbọ́n wà pẹlu onirẹlẹ.
3 Otitọ aduro-ṣinṣin ni yio ma tọ́ wọn; ṣugbọn arekereke awọn olurekọja ni yio pa wọn run.
4 Ọrọ̀ kì ini anfani li ọjọ ibinu: ṣugbọn ododo ni igbani lọwọ ikú.
5 Ododo ẹni-pipé yio ma tọ́ ọ̀na rẹ̀: ṣugbọn enia buburu yio ṣubu ninu ìwabuburu rẹ̀.
6 Ododo awọn aduro-ṣinṣin yio gbà wọn là: ṣugbọn awọn olurekọja li a o mu ninu iṣekuṣe wọn:
7 Nigbati enia buburu ba kú, ireti rẹ̀ a dasan, ireti awọn alaiṣedede enia a si dasan.
8 A yọ olododo kuro ninu iyọnu, enia buburu a si bọ si ipò rẹ̀.
9 Ẹnu li agabagebe ifi pa aladugbo rẹ̀: ṣugbọn ìmọ li a o fi gbà awọn olododo silẹ.
10 Nigbati o ba nṣe rere fun olododo, ilu a yọ̀: nigbati enia buburu ba ṣegbe, igbe-ayọ̀ a ta.
11 Nipa ibukún aduro-ṣinṣin ilu a gbé lèke: ṣugbọn a bì i ṣubu nipa ẹnu enia buburu.
12 Ẹniti oye kù fun gàn ọmọnikeji rẹ̀: ṣugbọn ẹni oye a pa ẹnu rẹ̀ mọ́.
13 Ẹniti nṣofofo fi ọ̀ran ipamọ́ hàn; ṣugbọn ẹniti nṣe olõtọ-ọkàn a pa ọ̀rọ na mọ́.
14 Nibiti ìgbimọ kò si, awọn enia a ṣubu; ṣugbọn ninu ọ̀pọlọpọ ìgbimọ ni ailewu.
15 Ẹniti o ba ṣe onigbọwọ fun alejo, ni yio ri iyọnu; ẹniti o ba si korira iṣegbọwọ wà lailewu.
16 Obirin olore-ọfẹ gbà iyìn: bi alagbara enia ti igbà ọrọ̀.
17 Alãnu enia ṣe rere fun ara rẹ̀: ṣugbọn ìka-enia nyọ ẹran-ara rẹ̀ li ẹnu.
18 Enia buburu nṣiṣẹ ère-ẹ̀tan; ṣugbọn ẹniti ngbin ododo ni ère otitọ wà fun.
19 Bi ẹniti o duro ninu ododo ti ini ìye, bẽni ẹniti nlepa ibi, o nle e si ikú ara rẹ̀.
20 Awọn ti iṣe alarekereke aiya, irira ni loju Oluwa; ṣugbọn inu rẹ̀ dùn si awọn aduroṣinṣin:
21 Bi a tilẹ fi ọwọ so ọwọ, enia buburu kì yio lọ laijiya, ṣugbọn iru-ọmọ olododo li a o gbàla.
22 Bi oruka wura ni imu ẹlẹdẹ, bẽni arẹwà obirin ti kò moye.
23 Kiki rere ni ifẹ inu awọn olododo; ṣugbọn ibinu ni ireti awọn enia buburu.
24 Ẹnikan wà ti ntuka, sibẹ o mbi si i, enikan si wà ti nhawọ jù bi o ti yẹ lọ, ṣugbọn kiki si aini ni.
25 Ọkàn iṣore li a o mu sànra; ẹniti o mbomirin ni, ontikararẹ̀ li a o si bomirin pẹlu.
26 Ẹniti o ba dawọ ọkà duro, on li enia o fibu: ṣugbọn ibukún yio wà li ori ẹniti o tà a.
27 Ẹniti o fi ara balẹ wá rere, a ri ojurere: ṣugbọn ẹniti o nwá ibi kiri, o mbọ̀wá ba a.
28 Ẹniti o ba gbẹkẹle ọrọ̀ rẹ̀ yio ṣubu: ṣugbọn olododo yio ma gbà bi ẹka igi.
29 Ẹniti o ba yọ ile ara rẹ̀ li ẹnu yio jogun ofo: aṣiwere ni yio ma ṣe iranṣẹ fun ọlọgbọ́n aiya.
30 Eso ododo ni igi ìye; ẹniti o ba si yi ọkàn enia pada, ọlọgbọ́n ni.
31 Kiye si i a o san a fun olododo li aiye: melomelo li enia buburu ati ẹlẹṣẹ.

## ORI 12.

ẸNIKẸNI ti o fẹ ẹkọ́, o fẹ ìmọ: ṣugbọn ẹniti o korira ibawi, ẹranko ni.
2 Enia rere ni ojurere lọdọ Oluwa: ṣugbọn enia ete buburu ni yio dalẹbi.
3 A kì yio fi ẹsẹ enia mulẹ nipa ìwabuburu: ṣugbọn gbòngbo olododo kì yio fatu.
4 Obirin oniwa-rere li ade ọkọ rẹ̀: ṣugbọn eyi ti ndojuti ni dabi ọyún ninu egungun rẹ̀.
5 Iro olododo tọ́: ṣugbọn ìgbimọ awọn enia buburu, ẹ̀tan ni.
6 Ọ̀rọ enia buburu ni lati luba fun ẹ̀jẹ: ṣugbọn ẹnu aduro-ṣinṣin ni yio gbà wọn silẹ.

Digitized by Google

7 A bì enia buburu ṣubu, nwọn kò si si:
ṣugbọn ile olododo ni yio duro.
8 A o yìn enia gẹgẹ bi ọgbọ́n rẹ̀: ṣugbọn
ẹni alayidayida aiya li a o gàn.
9 Ẹniti a ngàn, ti o si ni ọmọ-ọdọ, o san
jù ẹniti nyìn ara rẹ̀ ti kò si ni onjẹ.
10 Olododo enia mọ̀ ãjo ẹmi ẹran rẹ̀:
ṣugbọn iyọ́nu awọn enia buburu, ìka ni.
11 Ẹniti o ro ilẹ rẹ̀ li a o fi onjẹ tẹlọrun:
ṣugbọn ẹniti ntọ̀ enia-lasan lẹhin ni oye
kù fun.
12 Enia buburu fẹ ilu-odi awọn enia
buburu: ṣugbọn gbòngbo olododo so eso.
13 Irekọja ète enia buburu li a fi idẹkùn
rẹ̀: ṣugbọn olododo yio yọ kuro ninu
iponju.
14 Nipa ère ẹnu enia li a o fi ohun rere
tẹ ẹ lọrun: ère-iṣẹ ọwọ enia li a o si san
fun u.
15 Ọ̀na aṣiwere tọ li oju ara rẹ̀: ṣugbọn
ẹniti o fetisi ìgbimọ li ọlọgbọ́n.
16 Ibinu aṣiwere kò pẹ imọ̀: ṣugbọn
amoye enia bò itiju mọlẹ.
17 Ẹniti o sọ otitọ, o fi ododo hàn jade;
ṣugbọn ẹlẹri eke, ẹ̀tan.
18 Awọn kan mbẹ ti nyara sọ̀rọ lasan bi
igunni idà; ṣugbọn ahọn ọlọgbọ́n, ilera ni.
19 Ete otitọ li a o mu duro lailai;
ṣugbọn ahọn eke, ìgba diẹ ni.
20 Ẹtan wà li aiya awọn ti nrò ibi:
ṣugbọn fun awọn ìgbimọ alafia, ayọ̀ ni.
21 Kò si ibi kan ti yio ba olododo;
ṣugbọn awọn enia buburu ni yio kún fun
ibi.
22 Irira loju Oluwa li ahọn eke; ṣugbọn
awọn ti nṣe rere ni didùn-inu rẹ̀.
23 Ọlọgbọ́n enia pa ìmọ mọ: ṣugbọn
aiya awọn aṣiwere nkede iwere.
24 Ọwọ alãpọn ni yio ṣe akoso; ṣugbọn
ọlẹ ni yio wà labẹ irú-sisìn.
25 Ibinujẹ li aiya enia ni idori rẹ̀ kọ
odò; ṣugbọn ọ̀rọ rere ni imu u yọ̀.
26 Olododo tọ́ aladugbo rẹ̀ si ọ̀na; ṣu-
gbọn ọ̀na awọn enia buburu tàn wọn jẹ.
27 Ọlẹ enia kò mu ohun ọdẹ rẹ̀; ṣugbọn
lati jẹ alãpọn enia, ọrọ̀ iyebiye ni.
28 Li ọ̀na olododo ni ìye; ikú kò si loju
ọ̀na otitọ,

## ORI 13.

ỌLỌGBỌ́N ọmọ gbà ẹkọ́ baba rẹ̀ ṣugbọn
ẹlẹgàn kò gbọ́ ibawi.
2 Enia yio jẹ rere nipa ère ẹnu rẹ̀;
ṣugbọn ifẹ ọkàn awọn olurekọja ni ìwa-
agbara.
3 Ẹniti o pa ẹnu rẹ̀ mọ́, o pa ọmi rẹ̀
mọ́; ṣugbọn ẹniti o ṣi ète rẹ̀ pupọ yio ni
iparun.
4 Ọkàn ọlẹ nfẹ, kò si ri nkan; ṣugbọn
ọkàn awọn alãpọn li a o mu sanra.
5 Olododo korira ẹ̀tan; ṣugbọn enia bu-
buru mu ni hu ìwa irira on itiju.
6 Ododo pa aduro-ṣinṣin li ọ̀na mọ́;
ṣugbọn ìwa-buburu ni imuni ṣubu sinu
ẹ̀ṣẹ.
7 Ẹnikan wà ti o nfi ara rẹ̀ ṣe ọlọrọ̀,
ṣugbọn kò ni nkan; ẹnikan wà ti o nfi ara
rẹ̀ ṣe talaka ṣugbọn o li ọrọ̀ pupọ.
8 Irapada ẹmi enia li ọrọ̀ rẹ̀; ṣugbọn
olupọnju kò kiyesi ibawi.
9 Imọlẹ olododo nfi ayọ̀ jò; ṣugbọn fi-
tila enia buburu li a o pa.
10 Nipa kiki igberaga ni ìja ti iwá;
ṣugbọn lọdọ awọn ti a fi ìmọ hàn li ọgbọ́n
wà.
11 Ọrọ̀ ti a fi ìwa-asan ni yio fàsẹhin;
ṣugbọn ẹniti o fi iṣẹ-ọwọ kojọ ni yio ma pọ̀
si i.
12 Ireti pipẹ mu ọkàn ṣàisan; ṣugbọn
nigbati ifẹ ba de, igi ìye ni.
13 Ẹnikan ti o ba gàn ọ̀rọ na li a o
parun: ṣugbọn ẹniti o bẹ̀ru ofin na, li a o
san pada fun.
14 Ofin ọlọgbọ́n li orisun ìye, lati kuro
ninu okùn ikú.
15 Oye rere fi ojurere fun ni; ṣugbọn
ọ̀na awọn olurekọja ṣoro.
16 Gbogbo amoye enia ni nfi ìmọ ṣiṣẹ;
ṣugbọn aṣiwere tan were rẹ̀ kalẹ.
17 Oniṣẹ buburu bọ́ sinu iponju; ṣugbọn
olõtọ ikọ̀ mu ilera wá.
18 Oṣi ati itiju ni fun ẹniti o kọ̀ ẹkọ́;
ṣugbọn ẹniti o ba fetisi ibawi li a o bu ọlá
fun.
19 Ifẹ ti a muṣẹ dùnmọ ọkàn; ṣugbọn
irira ni fun aṣiwere lati kuro ninu ibi.
20 Ẹniti o mba ọlọgbọ́n rìn yio gbọ́n;
ṣugbọn ẹgbẹ awọn aṣiwere ni yio ṣegbe.
21 Ibi nlepa awọn ẹlẹṣẹ̀; ṣugbọn fun
awọn olododo, rere li a o ma fi san a.
22 Enia rere fi ogún silẹ fun awọn ọmọ
ọmọ rẹ̀; ṣugbọn ọrọ̀ ẹlẹṣẹ̀ li a tò jọ fun
olododo,
23 Onjẹ pupọ li o wà ni ilẹ titun awọn
talaka; ṣugbọn awọn kan wà ti a nparun
nitori aini idajọ;
24 Ẹniti o ba fà ọwọ paṣan sẹhin, o ko-
rira ọmọ rẹ̀; ṣugbọn ẹniti o fẹ ẹ a ma tète
nà a.
25 Olododo jẹ to itẹrun ọkàn rẹ̀; ṣugbọn
inu awọn enia buburu ni yio ṣe alaini.

Digitized by Google

## ORI 14.

OLUKULUKU ọlọgbọ́n obirin ni kọ́ ile
rẹ̀: ṣugbọn aṣiwere a fi ọwọ ara rẹ̀
fà a lulẹ.
2 Ẹniti o nrìn ni iduroṣiṣin rẹ̀ o bẹ̀ru
Oluwa: ṣugbọn ẹniti o ṣe arekereke li ọ̀na
rẹ̀, o gàn a.
3 Li ẹnu aṣiwere ni paṣan igberaga;
ṣugbọn ète awọn ọlọgbọ́n ni yio pa wọn
mọ́.
4 Nibiti malu kò si, ibujẹ a di ofo: ṣu-
gbọn ibisi pupọ mbẹ nipa agbara malu.
5 Ẹlẹri olõtọ kò jẹ ṣeke: ṣugbọn ẹ̀tan li
ẹlẹri eke ima sọ jade.
6 Ẹlẹgan nwá ọgbọ́n, kò si ri i: ṣugbọn
ìmọ kò ṣoro fun ẹniti oye ye.
7 Kuro niwaju aṣiwere, ati lọdọ ẹniti kò
ni ète ìmọ.
8 Ọgbọ́n amoye ni ati moye ọ̀na rẹ̀:
ṣugbọn iwere awọn aṣiwere li ẹ̀tan.
9 Aṣiwere nfi ẹbi-ẹ̀ṣẹ ṣẹsin: ṣugbọn oju-
rere wà larin awọn olododo.
10 Aiya mọ̀ ikoro ara rẹ̀; alejo kò si ni
iṣe pẹlu ayọ̀ rẹ̀.
11 Ile enia buburu li a o run: ṣugbọn
agọ ẹni diduroṣinṣin ni yio ma gbilẹ.
12 Ọ̀na kan wà ti o dabi ẹnipe o dara li
oju enia, ṣugbọn opin rẹ̀ li ọ̀na ikú.
13 Ninu ẹrín pẹlu, aiya a ma kãnu; ati
li opin ayọ̀, a di ibinujẹ.
14 Apadasẹhin li aiya ni itẹlọrun lati
inu ọ̀na ara rẹ̀: ṣugbọn enia rere lati inu
ohun ti iṣe tirẹ̀.
15 Òpe enia gbà ọ̀rọ gbogbo gbọ́: ṣugbọn
amoye enia wọ̀n ọ̀na ara rẹ̀ rere.
16 Ọlọgbọ́n enia bẹ̀ru, o si kuro ninu
ibi; ṣugbọn aṣiwẹ̀re gberaga, o si da ara
rẹ̀ loju.
17 Ẹniti o ba tete binu, huwa wère; ẹni
eletè buburu li a korira.
18 Awọn òpe jogun iwère; ṣugbọn awọn
amoye li a fi ìmọ de li ade.
19 Awọn ẹni-buburu tẹriba niwaju awọn
ẹnirere; ati awọn enia bubura li ẹnu-ọ̀na
awọn olododo.
20 A tilẹ korira talaka lati ọdọ aladugbo
rẹ̀ wá: ṣugbọn ọlọrọ̀ ni ọrẹ́ pupọ.
21 Ẹniti o kẹgàn ẹnikeji rẹ̀, o ṣẹ̀: ṣu-
gbọn ẹniti o ba ṣãnu fun awọn talaka,
ibukún ni fun u.
22 Awọn ti ngbìmọ buburu kò ha ṣina
bi? ṣugbọn ãnu ati otitọ ni fun awọn ti
ngbìmọ ire.
23 Ninu gbogbo lãla li ère pupọ wà:
ṣugbọn ọ̀rọ-ẹnu, lasan ni.
24 Adé awọn ọlọgbọ́n li ọrọ̀ wọn: ṣu-
gbọn iwère awọn aṣiwère ni wère.
25 Olõtọ ẹlẹri gbà ọkàn silẹ: ṣugbọn
ẹlẹri ẹ̀tan sọ̀rọ eke.
26 Ni ibẹ̀ru Oluwa ni igbẹkẹle ti o
lagbara: yio si jẹ ibi àbo fun awọn ọmọ
rẹ̀.
27 Ibẹ̀ru Oluwa li orisun ìye, lati kuro
ninu ikẹkùn ikú.
28 Ninu ọ̀pọlọpọ enia li ọlá ọba: ṣugbọn
ninu enia diẹ ni iparun ijoye.
29 Ẹniti o ba lọra ati binu, o ni ìmọ
pupọ; ṣugbọn ẹniti o ba yara binu o gbe
wère leke.
30 Aiya ti o yè korokoro ni ìye ara;
ṣugbọn ilara ni ibajẹ egungun.
31 Ẹniti o ba nni talaka lara, o gàn
Ẹlẹda rẹ̀; ṣugbọn ẹniti o ṣãnu fun talaka
o bu ọlá fun u.
32 A pa enia buburu run ninu ìwa-bu-
buru rẹ̀; ṣugbọn olododo ni ireti ninu ikú
rẹ̀.
33 Ọgbọ́n fi idi kalẹ li aiya ẹniti o moye;
ṣugbọn a fi i hàn laiya awọn aṣiwère.
34 Ododo ni igbé orilẹ-ède leke; ṣugbọn
ẹ̀ṣẹ li ẹ̀gan orilẹ-ède.
35 Ojurere ọba mbẹ li ọdọ ọlọgbọ́n iran-
ṣẹ; ṣugbọn ibinu rẹ̀ si iranṣẹ ti nhùwa
itiju.

## ORI 15.

IDAHÙN pẹlẹ yi ibinu pada; ṣugbọn ọ̀rọ
lile ni irú ibinu soke.
2 Ahọn ọlọgbọ́n nlò ìmọ rere: ṣugbọn
ẹnu aṣiwère a ma gufẹ wère.
3 Oju Oluwa mbẹ ni ibi gbogbo, o nwò
awọn ẹni-buburu ati ẹni-rere.
4 Ahọn imularada ni igi ìye: ṣugbọn
ayidayida ninu rẹ̀ ni ibajẹ ọkàn.
5 Aṣiwère gàn ẹkọ́ baba rẹ̀: ṣugbọn ẹniti
o ba feti si ibawi li o moye.
6 Ni ile olododo li ọ̀pọlọpọ iṣura: ṣu-
gbọn ninu òwò enia buburu ni iyọnu.
7 Ete ọlọgbọ́n tan ìmọ kalẹ: ṣugbọn
aiya aṣiwère kì iṣe bẹ̃.
8 Ẹbọ awọn enia buburu, irira ni loju
Oluwa; ṣugbọn adura awọn aduroṣinṣin
ni didùn-inu rẹ̀.
9 Ọ̀na enia buburu, irira ni loju Oluwa;
ṣugbọn o fẹ ẹniti ntọ̀ ododo lẹhin.
10 Ikilọ kikan wà fun ẹniti o kọ̀ ọ̀na
silẹ; ẹniti o ba si korira ibawi yio kú.
11 Ipo-okú ati iparun ṣi silẹ niwaju
Oluwa; njẹ melomelo li aiya awọn ọmọ
enia.



Digitized by Google

12 Ẹlẹgàn kò fẹ ẹniti mba a wi; bẹ̃ni kì
yio tọ̀ awọn ọlọgbọ́n lọ.
13 Inu-didùn a mu oju daraya; ṣugbọn
nipa ibinujẹ aiya, ọkàn a rẹ̀wẹsi.
14 Aiya ẹniti oye ye nṣe afẹri ìmọ; ṣu-
gbọn ẹnu aṣiwère nfi wère bọ́ ara rẹ̀.
15 Gbogbo ọjọ olupọnju ni ibi; ṣugbọn
oninu-didùn njẹ alafia nigbagbogbo.
16 Diẹ pẹlu ibẹ̀ru Oluwa, o san jù iṣura
pupọ ti on ti iyọnu ninu rẹ̀.
17 Onjẹ ewebẹ̀ nibiti ifẹ wà, o san jù
abọpa malu lọ ati irira pẹlu rẹ̀.
18 Abinu enia rú asọ̀ soke; ṣugbọn ẹniti
o lọra ati binu, o tù ìja ninu.
19 Ọ̀na ọlẹ dabi igbo ẹgún; ṣugbọn ọ̀na
olododo kunakuna ni.
20 Ọlọgbọ́n ọmọ ṣe ayọ̀ baba; ṣugbọn
aṣiwère enia gàn iya rẹ̀.
21 Ayọ̀ ni wère fun ẹniti oye kù fun;
ṣugbọn ẹni-oye a ma rìn ni iduroṣinṣin.
22 Laisi ìgbimọ, èro a dasan; ṣugbọn li
ọ̀pọlọpọ ìgbimọ, nwọn a fi idi mulẹ.
23 Enia ni ayọ̀ nipa idahùn ẹnu rẹ̀; ati
ọ̀rọ kan li akoko rẹ̀, o ti wọ̀ to?
24 Ọ̀na ìye lọ soke fun ọlọgbọ́n, ki o le
kuro ni ipo-okú nisalẹ.
25 Oluwa yio run ile agberaga; ṣugbọn
yio fi ìpalà opó kalẹ.
26 Ìro inu enia buburu, irira ni loju
Oluwa; ṣugbọn mimọ́ ni ọ̀rọ didùn niwaju
rẹ̀.
27 Ẹniti o njẹ ère aiṣododo, o nyọ ile ara
rẹ̀ lẹnu; ṣugbọn ẹniti o korira ẹ̀bun yio yè.
28 Aiya olododo ṣe àṣaro lati dahùn;
ṣugbọn ẹnu enia buburu ngufẹ ohun ibi
jade.
29 Oluwa jina si awọn enia-buburu;
ṣugbọn o gbọ́ adura awọn olododo.
30 Imọlẹ oju mu inu dùn; ihin rere si
mu egungun sanra.
31 Ẹniti o ba gbọ́ ibawi ìye, a joko lãrin
awọn ọlọgbọ́n.
32 Ẹniti o kọ̀ ẹkọ́, o gàn ọkàn ara rẹ̀:
ṣugbọn ẹniti o ba gbọ́ ibawi, o ni imoye.
33 Ibẹ̀ru Oluwa li ẹkọ́ ọgbọ́n; ati ṣãju
ọlá ni irẹlẹ.

## ORI 16.

IMURA aiya, ti enia ni, ṣugbọn lati ọdọ
Oluwa ni idahùn ahọn.
2 Gbogbo ọ̀na enia li o mọ́ li oju ara rẹ̀;
ṣugbọn Oluwa li o ndiwọ̀n ọkàn.
3 Ká iṣẹ rẹ le Oluwa lọwọ, a o si fi idi
ìro-inu rẹ kalẹ.
4 Oluwa ti ṣe ohun gbogbo fun ipinnu
rẹ̀: nitõtọ, awọn enia buburu fun ọjọ ibi.
5 Olukuluku enia ti o gberaga li aiya,
irira ni loju Oluwa: bi a tilẹ fi ọwọ so ọwọ,
kì yio wà laijiya.
6 Nipa ãnu ati otitọ a bò ẹ̀ṣẹ mọlẹ; ati
nipa ibẹ̀ru Oluwa, enia a kuro ninu ibi.
7 Nigbati ọ̀na enia ba wù Oluwa, On a
mu awọn ọtá rẹ̀ pãpa wà pẹlu rẹ̀ li alafia.
8 Diẹ pẹlu ododo, o san jù ọrọ̀ nla lọ
laisi ẹtọ́.
9 Aiya enia ni ngbìmọ ọ̀na rẹ̀, ṣugbọn
Oluwa li o ntọ́ itẹlẹ rẹ̀.
10 Ọrọ isọtẹlẹ mbẹ li ète ọba: ẹnu rẹ̀ kì
iṣẹ̀ ni idajọ.
11 Iwọn ati òṣuwọn otitọ ni ti Oluwa:
gbogbo okuta-ìwọn àpo, iṣẹ rẹ̀ ni.
12 Irira ni fun awọn ọba lati ṣe buburu:
nitoripe nipa ododo li a ti fi idi itẹ́ kalẹ.
13 Ète ododo ni didùn-inu awọn ọba:
nwọn si fẹ ẹniti nsọ̀rọ titọ.
14 Ibinu ọba dabi iranṣẹ ikú: ṣugbọn
ọlọgbọ́n enia ni yio tù u.
15 Ni imọlẹ oju ọba ni ìye; ojurere rẹ̀ si
dabi awọsanma òjo arọkuro.
16 Lati ni ọgbọ́n, melomelo li o san jù
wura lọ; ati lati ni oye, melomelo li o dara
jù fadaka lọ.
17 Òpopo-ọ̀na awọn aduro-ṣinṣin ni ati
kuro ninu ibi: ẹniti o pa ọ̀na rẹ̀ mọ́, o pa
ọkàn rẹ̀ mọ́.
18 Igberaga ni iṣaju iparun, agidi ọkàn
ni iṣaju iṣubu.
19 O san lati ṣe onirẹlẹ ọkàn pẹlu awọn
talaka, jù ati ba awọn agberaga pin ikó-
gun.
20 Ẹniti o fi oye ṣe ọ̀ran yio ri ire; ẹniti
o si gbẹkẹ le Oluwa, ibukún ni fun u.
21 Ọlọgbọ́n aiya li a o pè li amoye:
didùn-ète a si ma mu ẹkọ́ pọ̀.
22 Oye li orisun ìye fun ẹniti o ni i:
ṣugbọn ẹkọ́ aṣiwère ni iwère.
23 Aiya ọlọgbọ́n mu ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ gbọ́n, o
si mu ẹkọ́ pọ̀ li ète rẹ̀.
24 Ọ̀rọ didùn dabi afara oyin, o dùn mọ
ọkàn, o si ṣe ilera fun egungun.
25 Ọ̀na kan wà ti o dabi ẹnipe o dara
fun enia, ṣugbọn opin rẹ̀ li ọ̀na ikú.
26 Ọ̀kàn ti o nṣiṣẹ, o nṣiṣẹ fun ara rẹ̀;
nitoripe ẹnu ara rẹ̀ li o nsún u ṣe e.
27 Enia-buburu hù ìwa-ibi jade, ati li
ète rẹ̀ bi ẹnipe iná jijo li o wà nibẹ.
28 Alayidayida enia dá ìja silẹ: asọ̀rọ-
kẹlẹ yà awọn ọrẹ́ ni ipa.
29 Ẹni ìwa-agbara tàn aladugbo rẹ̀, a si
mu u lọ si ipa-ọ̀na ti kò dara.
30 On a di oju rẹ̀ lati gbèro ohun ayida-
yida: o ká ète rẹ̀ sinu, o pari ohun buburu.

Digitized by Google

31 Ade ogo li ori ewú, bi a ba ri i li ọ̀na
ododo.
32 Ẹniti o lọra ati binu, o san jù alagba-
ra lọ; ẹniti o si ṣe akoso ẹmi rẹ̀, o jù ẹniti
o ṣẹgun ilu lọ.
33 A ṣẹ́ keke dà si iṣẹpo aṣọ; ṣugbọn
gbogbo idajọ rẹ̀ lọwọ Oluwa ni.

## ORI 17.

OKELE gbigbẹ, ti on ti alafia, o san jù
ile ti o kún fun ẹran-pipa ti on ti ìja.
2 Ọlọgbọ́n iranṣẹ yio ṣe olori ọmọ ti
nhùwa itiju, yio si pin ogún lãrin awọn
arakọnrin.
3 Koro ni fun fadaka, ati ileru fun wura:
ṣùgbọ́n Oluwa ndan aiya wò.
4 Oluṣe buburu fetisi ète eke; ẹni-eke a
si ma kiyesi ọ̀rọ ahọn buburu.
5 Ẹnikẹni ti o ba sín olupọnju jẹ, o gàn
Ẹlẹda rẹ̀: ẹniti o ba si nyọ̀ si wahala kì
yio wà li aijiya.
6 Ọmọ ọmọ li ade arugbo: ogo awọn
ọmọ si ni baba wọn.
7 Ọ̀rọ daradara kò yẹ fun aṣiwère; bẽli
ète eke kò yẹ fun ọmọ-alade.
8 Okuta iyebiye jẹ ẹ̀bun li oju ẹniti o ni
i; nibikibi ti o yi si, a ṣe rere.
9 Ẹniti o bò ẹ̀ṣẹ mọlẹ, o nwá ifẹ; ṣugbọn
ẹniti o tun ọ̀ran hú silẹ, o yà ọrẹ́ nipa.
10 Ibawi wọ̀ inu ọlọgbọ́n jù ọgọrun
paṣan lọ ninu aṣiwère.
11 Ẹni-ọ̀tẹ a ma wá kiki ibi kiri; nito-
rina iranṣẹ ìka li a o ran si i.
12 O yá ki ẹranko beari ti a kó li ọmọ
ki o pade enia, jù aṣiwère lọ ninu wère rẹ̀.
13 Ẹnikẹni ti o ba fi ibi san ire, ibi kì
yio kuro ninu ile rẹ̀.
14 Ẹniti o daju fun omi dabi olupilẹṣẹ
ìja; nitorina fi ìja silẹ ki o to di nla.
15 Ẹniti o da enia buburu lare, ati ẹniti
o da olododo lẹbi, ani awọn mejeji irira ni
loju Oluwa.
16 Nitori kini iye owo yio ṣe wà lọwọ
aṣiwère lati rà ọgbọ́n, sa wò o, kò ni oye?
17 Ọrẹ́ a ma fẹni nigbagbogbo, ṣugbọn
arakọnrin li a bi fun ìgba ipọnju.
18 Enia ti oye kù fun, a ṣe onigbọwọ, a
si fi ara sọfà niwaju ọrẹ́ rẹ̀.
19 Ẹniti o fẹ ìja, o fẹ ẹ̀ṣẹ; ẹniti o kọ́
ẹnu-ọ̀na rẹ̀ ga, o nwá iparun.
20 Ẹniti o ni ayidayida ọkàn kì yio ri
ire: ati ẹniti o ni ahọn ọ̀rọ-meji, a bọ sinu
ibi.
21 Ẹniti o bi aṣiwère, o bi i si ibinujẹ
rẹ̀; baba aṣiwère kò si li ayọ̀.
22 Inu-didùn mu imularada rere wá:
ṣugbọn ibinujẹ ọkàn mu egungun gbẹ.
23 Enia buburu mu ẹ̀bun lati iṣẹpo-aṣọ
lati yi ọ̀na idajọ pada.
24 Ọgbọ́n wà niwaju ẹniti o moye; ṣu-
gbọn oju aṣiwère mbẹ li opin ilẹ-aiye.
25 Aṣiwère ọmọ ni ibinujẹ baba rẹ̀, ati
kikoro ọkàn fun iya ti o bi i.
26 Pẹlupẹlu kò dara ki a ṣẹ́ olotitọ ni iṣẹ́,
tabi ki a lu ọmọ-alade nitori iṣedẽde.
27 Ẹniti o ni ìmọ, a ṣẹ́ ọ̀rọ rẹ̀ kù: ọlọ-
kàn tutu si li amoye enia.
28 Lõtọ, aṣiwère, nigbati o ba pa ẹnu rẹ̀
mọ́, a kà a si ọlọgbọ́n; ẹniti o ba pa ẹnu
rẹ̀ mọ́ si li amoye.

## ORI 18.

ENITI o yà ara rẹ̀ sọtọ̀ yio lepa ifẹ ara
rẹ̀, yio si kọju ìja nla si ohunkohun ti
iṣe ti oye.
2 Aṣiwère kò ni inu-didùn si imoye,
ṣugbọn ki o le fi aiya ara rẹ̀ hàn.
3 Nigbati enia-buburu ba de, nigbana ni
ẹ̀gan de, ati pẹlu ẹ̀gan ni itiju.
4 Ọ̀rọ ẹnu enia dabi omi jijìn, orisun
ọgbọ́n bi odò ṣiṣàn.
5 Kò dara lati ṣe ojusaju enia-buburu,
lati bì olododo ṣubu ni idajọ.
6 Ete aṣiwère bọ sinu ìja, ẹnu rẹ̀ a si ma
pè ìna wá.
7 Ẹnu aṣiwère ni iparun rẹ̀, ète rẹ̀ si ni
ikẹkùn ọkàn rẹ̀.
8 Ọ̀rọ olofofo dabi adidùn, nwọn a si wọ
isalẹ inu lọ.
9 Ẹniti o lọra pẹlu ni iṣẹ rẹ̀, arakọnrin
jẹguduragudu enia ni.
10 Orukọ Oluwa, ile-iṣọ agbara ni:
Olododo sá wọ inu rẹ̀, o si là.
11 Ọrọ̀ ọlọrọ̀ ni ilu-agbara rẹ̀, o si dabi
odi giga li oju ara rẹ̀.
12 Ṣaju iparun, aiya enia a ṣe agidi,
ṣaju ọlá si ni irẹlẹ.
13 Ẹniti o ba dahùn ọ̀rọ ki o to gbọ́,
wère ati itiju ni fun u.
14 Ọkàn enia yio faiyàrán ailera rẹ̀;
ṣugbọn ọkàn ti o rẹwẹsi, tani yio gbà a.
15 Aiya amoye ni ìmọ; eti ọlọgbọ́n a si
ma ṣe afẹri ìmọ.
16 Ọrẹ enia a ma fi àye fun u, a si mu u
wá siwaju awọn enia nla.
17 Ẹnikini ninu ẹjọ rẹ̀ a dabi ẹnipe o
jare, ṣugbọn ẹnikeji rẹ̀ a wá, a si hudi rẹ̀
silẹ.
18 Keké mu ìja pari, a si làja lãrin awọn
alagbara.

Digitized by Google

19 Arakọnrin ti a ṣẹ̀ si, o ṣoro jù ilu olo-
di lọ: ìja wọn si dabi ọpá idabu ãfin.
20 Ọrọ ẹnu enia ni yio mu inu rẹ̀ tutu:
ibisi ẹnu rẹ̀ li a o si fi tù u ninu.
21 Ikú ati ìye mbẹ ni ipa ahọn: awọn
ẹniti o ba si nlò o yio jẹ ẽre rẹ̀.
22 Ẹnikẹni ti o ri aya fẹ, o ri ohun rere,
o-si ri ojurere lọdọ Oluwa.
23 Talaka a ma bẹ̀ ẹ̀bẹ; ṣugbọn ọlọrọ̀ a
ma fi ikanra dahùn.
24 Ẹniti o ni ọrẹ́ pupọ, o ṣe e si iparun
ara rẹ̀; ọrẹ́ kan si mbẹ ti o fi ara mọni jù
arakọnrin lọ.

## ORI 19.

TALAKA ti nrìn ninu ìwa-titọ rẹ̀, o san
jù ẹniti o nṣe arekereke li ète rẹ̀ lọ, ti
o si nṣe wère.
2 Pẹlupẹlu, ọkàn laini ìmọ, kò dara;
ẹniti o ba si fi ẹsẹ rẹ̀ yara yio ṣubu.
3 Wère enia yi ọ̀na rẹ̀ po: nigbana ni
aiya rẹ̀ binu si Oluwa.
4 Ọrọ̀ fà ọrẹ́ pupọ: ṣugbọn talaka di yi-
yà kuro lọdọ aladugbo rẹ̀.
5 Ẹlẹri eke kì yio lọ laijiya, ati ẹniti o
si nṣeke kì yio mu u jẹ.
6 Ọpọlọpọ ni yio ma bẹ̀bẹ ojurere ọmọ-
alade: olukuluku enia ni si iṣe ọrẹ́ ẹniti
ntani li ọrẹ.
7 Gbogbo awọn arakọnrin talaka ni iko-
rira rẹ̀: melomelo ni awọn ọrẹ́ rẹ̀ yio ha
jina si i? o ntẹle ọ̀rọ wọn, ṣugbọn nwọn kò
si.
8 Ẹniti o gbọ́n, o fẹ ọkàn ara rẹ̀: ẹniti o
pa oye mọ́ yio ri rere.
9 Ẹlẹri eke kì yio lọ laijiya, ẹniti o si
nṣeke yio ṣegbe.
10 Ohun rere kò yẹ fun aṣiwère; tabi
melomelo fun iranṣẹ lati ṣe olori awọn
ijoye.
11 Imoye enia mu u lọra ati binu; ogo
rẹ̀ si ni lati ré ẹ̀ṣẹ kọja.
12 Ibinu ọba dabi igbe kiniun; ṣugbọn
ọjurere rẹ̀ dabi ìri lara koriko.
13 Aṣiwère ọmọ ni ibanujẹ baba rẹ̀: ìja
aya dabi ọ̀ṣọrọ ọ̀jo.
14 Ile ati ọrọ̀ li ogún awọn baba: ṣu-
gbọn amoye aya, lati ọdọ Oluwa wá ni.
15 Imẹlẹ mu ni sun orun fọnfọn; ọkàn
ọlẹ li ebi yio si pa.
16 Ẹniti o pa ofin mọ́, o pa ọkàn ara rẹ̀
mọ́; ṣugbọn ẹniti o ba kẹgàn ọ̀na rẹ̀ yio
kú.
17 Ẹniti o ṣãnu fun talaka Oluwa li o
win; ati iṣeun rẹ̀ yio san a pada fun u.
18 Nà ọmọ rẹ nigbati ireti wà, má si ṣe
gbe ọkán rẹ le ati pa a.
19 Onibinu nla ni yio jiya; nitoripe bi
iwọ ba gbà a, sibẹ iwọ o tun ṣe e.
20 Fetisi ìmọ ki o si gbà ẹkọ́, ki iwọ ki
o le gbọ́n ni igbẹhin rẹ.
21 Ete pupọ li o wà li aiya enia; ṣugbọn
ìgbimọ Oluwa, eyini ni yio duro.
22 Ẹwà enia ni iṣeun rẹ̀: talaka enia si
san jù eleke lọ.
23 Ibẹ̀ru Oluwa tẹ̀ si ìye: ẹniti o ni i
yio joko ni itẹlọrun; a kì yio fi ibi bẹ̀ ẹ
wó.
24 Imẹlẹ enia kì ọwọ rẹ̀ sinu iṣasun, kò
si le yọ ọ jade pada wá si ẹnu ara rẹ̀.
25 Lu ẹlẹgàn, ọ̀pe yio si kiyesi ara: si
ba ẹniti o moye wi, oye ìmọ yio si ye e.
26 Ẹniti o ba nṣika si baba rẹ̀, ti o si le
iya rẹ̀ jade, on li ọmọ ti nṣe itiju, ti o si
mu ẹ̀gan wá.
27 Ọmọ mi, dẹkun ati fetisi ẹkọ́ ti imu
ni ṣìna kuro ninu ọ̀rọ ìmọ.
28 Ẹlẹri buburu fi idajọ ṣẹsin: ẹnu enia
buburu si gbe aiṣedẽde mì.
29 A pèse ọ̀rọ-idajọ fun awọn ẹlẹgàn, ati
paṣan fun ẹ̀hin awọn aṣiwère.

## ORI 20.

ẸLẸYA li ọti-waini, alariwo li ọti lile,
ẹnikẹni ti a ba fi tanjẹ kò gbọ́n.
2 Ibẹ̀ru ọba dabi igbe kiniun: ẹnikẹni
ti o ba mu u binu, o ṣẹ̀ si ọkàn ara rẹ̀.
3 Ọlá ni fun enia lati ṣiwọ kuro ninu
ìja: ṣugbọn olukuluku aṣiwère ni ima ja
ìja nla.
4 Ọlẹ kò jẹ tú ilẹ nitori otutu; nitorina
ni yio fi ma ṣagbe nigba ikore, kì yio si ni
nkan.
5 Ìmọ ninu ọkàn enia dabi omi jijin;
ṣugbọn amoye enia ni ifà a jade.
6 Ọpọlọpọ enia ni ima fọnrere, olukulu-
ku ore ara rẹ̀: ṣugbọn olõtọ enia tani yio
rí i.
7 Olõtọ enia nrìn ninu iwa-titọ rẹ̀: ibu-
kún si ni fun awọn ọmọ rẹ̀ lẹhin rẹ̀!
8 Ọba ti o joko lori itẹ́ idajọ, o fi oju rẹ̀
fọ́n ìwa-ibi gbogbo ka.
9 Tali o le wipe, Mo ti mu aiya mi mọ́,
emi ti mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ mi?
10 Ìwọn miran, ati ọ̀ṣuwọn miran, ba-
kanna ni mejeji ṣe irira loju Oluwa.
11 Iṣe ọmọde pãpa li a fi imọ̀ ọ, bi ìwa
rẹ̀ ṣe rere ati titọ.
12 Eti igbọ́ ati oju irí, Oluwa li o ti dá
awọn mejeji.
13 Máṣe fẹ orun sisùn, ki iwọ ki o má

Digitized by Google

ba di talaka ; şi oju rẹ, a o si fi onjẹ tẹ ọ
lọrùn.
14 Kò ni lãri, kò ni lãri li alabara iwi ;
şugbọn nigbati o ba bọ si ọ̀na rẹ̀, nigbana
ni işogo.
15 Wura wà ati iyùn ọ̀pọlọpọ : şugbọn
ète ìmọ, èlo iyebiye ni.
16 Gba aşọ rẹ̀, nitori ti o şe onigbọwọ
fun alejo, si gba ohun ẹrí lọwọ rẹ̀ fun ajeji
obirin.
17 Onjẹ ẹ̀tan dùn mọ enia ; şugbọn nì-
kẹhin, ẹnu rẹ̀ li a o fi tãra kún.
18 Igbimọ li a fi ifi idi ete gbogbo kalẹ :
ati pẹlu èro rere ni ki o şigun.
19 Ẹniti o ba nkiri bi olofofo a ma fi
ọ̀ran ìkọkọ hàn : má si şe ba ẹniti nşi ète
rẹ̀ şire.
20 Ẹnikẹni ti o ba bú baba rẹ̀ tabi iya
rẹ̀, fitila rẹ̀ li a o pa ninu òkunkun biribiri.
21 Ogún ti a yara jẹ latetekọşe, li a kì
yio bukún li opin rẹ̀.
22 Iwọ máşe wipe, Emi o gbẹsan ibi ;
şugbọn duro de Oluwa, on o si gbà ọ.
23 Ìwọn miran, ati òşuwọn miran, irira
ni loju Oluwa ; ìwọn irẹjẹ kò si dara.
24 Irin ti enia nrìn, lati ọdọ Oluwa ni ;
tani ninu awọn enia ti o le mọ̀ ọ̀na rẹ̀ ?
25 Idẹkùn ni fun enia lati yara şe ileri
mimọ́, ati lẹhin ẹjẹ́, ki o ma ronu.
26 Ọlọgbọ́n ọba a tú enia buburu ka, a
si mu ayika-kẹkẹ́ rẹ̀ kọja lori wọn.
27 Ẹmi enia ni fitila Oluwa, a ma şe
awari iyara inu.
28 Anu ati otitọ pa ọba mọ́ : ãnu li a si
fi ndi itẹ́ rẹ̀ mu.
29 Ogo awọn ọdọmọkọnrin li agbara
wọn : ẹwà awọn arugbo li ewú.
30 Apá ọgbẹ ni iwẹ̀ ibi nù kuro : bẹ̃ si
ni ìna ti o wọ̀ odò ikùn lọ.

ORI 21.

AIYA ọba mbẹ lọwọ Oluwa bi odò omi ;
on a si dari rẹ̀ si ìbikibi ti o wù u.
2 Gbogbo ọ̀na enia li o dara li oju ara rẹ̀ :
şugbọn Oluwa li o nşe amọ̀na ọkàn.
3 Lati şe ododo ati idajọ, o şe itẹwọgba
fun Oluwa jù ẹbọ lọ.
4 Gangan oju, ati igberaga aiya, ati itu-
lẹ̀ enia buburu, ẹ̀şẹ ni.
5 Ìronu alãpọn si kiki ọ̀pọ ni ; şugbọn ti
olukuluku ẹniti o yara, si kiki aini ni.
6 Ini işura nipa ahọn eke, o jẹ ẽmi ti a
ntì sihin tì sọhun lọwọ awọn ti nwá ikú
kiri.
7 Iwa-agbara awọn enia buburu ni yio
pa wọn run : nitori ti nwọn kọ̀ lati şe
idajọ.
8 Ẹnikẹni ti o nrìn ọ̀na ayidayida, enia
buburu ni ; şugbọn oninu funfun ni işẹ rẹ̀
tọ́.
9 O san lati joko ni igun òke àja, jù
pẹlu onija obirin lọ ninu ile ajumọgbe.
10 Ọkàn enia buburu nwá ibi kiri : ala-
dugbo rẹ̀ kò ri ojurere li oju rẹ̀.
11 Nigbati a ba jẹ ẹlẹgàn ni ìya, a sọ
òpe di ọlọgbọ́n : nigbati a ba si nkọ́ ọlọ-
gbọ́n, on o ma ni ìmọ.
12 Olododo kiyesi ile enia buburu : pe
ẹnikan wà ti yio bì enia buburu şubu sinu
iparun.
13 Ẹnikẹni ti o ba di eti rẹ̀ si igbe olu-
pọnju, ontikararẹ̀ yio ke pẹlu : şugbọn a
kì yio gbọ́.
14 Ọrẹ ikọkọ, o tù ibinu : ati ẹ̀bun ni
işẹpo-aşọ, o tù ibinu lile.
15 Ayọ̀ ni fun olododo lati şe idajọ :
şugbọn iparun ni fun awọn onişẹ ẹ̀şẹ.
16 Ẹniti o ba yà kuro li ọ̀na oye, yio ma
gbe inu ijọ awọn okú.
17 Ẹniti o ba fẹ afẹ, yio di talaka : ẹniti
o fẹ ọti-waini pẹlu ororo kò le lọrọ̀.
18 Enia buburu ni yio şe owo-irapada
fun olododo, ati olurekọja ni ipò ẹni di-
duro-şinşin.
19 O san lati joko li aginju jù pẹlu onija
obirin ati oşónu lọ.
20 Işura fifẹ ati ororo wà ni ibugbe
ọlọgbọ́n ; şugbọn enia aşiwère ná a bajẹ.
21 Ẹniti o ba tẹle ododo ati ãnu, a ri
ìye, ododo, ati ọlá.
22 Ọlọgbọ́n gùn odi ilu awọn alagbara,
a si fi idi agbara igbẹkẹle rẹ̀ jalẹ.
23 Ẹnikẹni ti o ba pa ẹnu ati ahọn rẹ̀
mọ́, o pa ọkàn rẹ̀ mọ́ kuro ninu iyọnu.
24 Agberaga ati agidi ẹlẹgàn li orukọ rẹ̀,
ẹniti nhùwa ninu ibinu pupọpupọ.
25 Ifẹ ọlẹ pa a ; nitoriti ọwọ rẹ̀ kọ̀ işẹ
şişe.
26 O nfi ilara şojukokoro ni gbogbo ọjọ :
şugbọn olododo a ma fi funni kì si idawọ-
duro.
27 Ẹbọ enia buburu, irira ni : melomelo
ni nigbati o mu u wá ti on ti ìwakiwa rẹ̀ ?
28 Ẹlẹri eke yio şegbe : şugbọn ẹniti o
gbọ́, yio ma sọrọ li aiyannu.
29 Enia buburu gbè oju rẹ̀ le : şugbọn
ẹni iduro-şinşin li o nmu ọ̀na rẹ̀ tọ́.
30 Kò si ọgbọ́n, kò si imoye, tabi ìgbimọ
si Oluwa.
31 A mura ẹşin silẹ de ọjọ ogun : şugbọn
işẹgun lati ọwọ Oluwa ni.

Digitized by Google

## ORI 22.

ORUKỌ rere sàn ni yiyàn jù ọrọ̀ pupọ lọ, ati ojurere ifẹ jù fadaka ati wura lọ.

2 Ọlọrọ̀ ati talaka pejọ pọ̀: Oluwa li ẹlẹda gbogbo wọn.

3 Ọlọgbọ́n enia ti ri ibi tẹlẹ, o si pa ara rẹ̀ mọ́: ṣugbọn awọn òpe a kọja, a si jẹ wọn niya.

4 Ere irẹlẹ ati ibẹ̀ru Oluwa li ọrọ̀, ọlá, ati ìye.

5 Ẹgún ati idẹkùn mbẹ li ọ̀na alayidayida: ẹniti o ba pa ọkàn rẹ̀ mọ́ yio jina si wọn.

6 Tọ́ ọmọde li ọ̀na ti yio tọ̀: nigbati o si dàgba tan, kì yio kuro ninu rẹ̀.

7 Ọlọrọ̀ ṣe olori olupọnju, ajigbese si ṣe iranṣẹ fun onigbese.

8 Ẹniti o ba funrugbin ẹ̀ṣẹ, yio ri asan ka: ọpá ibinu rẹ̀ si ti mura tan.

9 Ẹniti o li oju ãnu li a o bukun fun; nitoriti o fi ninu onjẹ rẹ̀ fun olupọnju.

10 Ṣá ẹlẹgàn tì sode, ìja yio si jade; nitõtọ ìja ati ẹ̀gan yio dẹkun.

11 Ẹniti o fẹ ìwa funfun aiya, ti o fẹ ọ̀rọ pẹlẹ, ọba yio ṣe ọrẹ́ rẹ̀.

12 Oju Oluwa pa ìmọ mọ́, o si yi ọ̀rọ olurekọja po.

13 Ọlẹ wipe, kiniun mbẹ lode, a o pa mi ni igboro.

14 Ẹnu awọn ajeji obirin, iho jijin ni; ẹniti a mbinu si lati ọdọ Oluwa wá ni yio ṣubu sinu rẹ̀.

15 Li aiya ọmọde ni wère dì si; ṣugbọn paṣan itọ́ni ni yio le e jina kuro lọdọ rẹ̀.

16 Ẹniti o nni talaka lara lati mu ọrọ̀ pọ̀, ti o si nta ọlọrọ̀ lọrẹ, yio di alaini bi o ti wu ki o ṣe.

17 Dẹti rẹ silẹ, ki o gbọ́ ọ̀rọ awọn ọlọgbọ́n, ki o si fi aiya rẹ si ẹkọ́ mi.

18 Nitori ohun didùn ni bi iwọ ba pa wọn mọ́ ni inu rẹ; nigbati a si pese wọn tan li ète rẹ.

19 Ki igbẹkẹle rẹ ki o le wà niti Oluwa, emi fi hàn ọ loni, ani fun ọ.

20 Emi kò ti kọwe ohun daradara si ọ ni igbimọ ati li ẹkọ́,

21 Ki emi ki o le mu ọ mọ̀ idaju ọ̀rọ otitọ; ki iwọ ki o le ma fi idahùn otitọ fun awọn ti o rán ọ?

22 Máṣe ja talaka li ole, nitori ti iṣe talaka: bẽni ki o má si ṣe ni olupọnju lara ni ibode:

23 Nitori Oluwa yio gbija wọn, yio si gbà ọkàn awọn ti ngbà lọwọ won.

24 Máṣe ba onibinu enia ṣe ọrẹ́; má si ṣe ba ọkọnrin oninu-fùfu rìn.

25 Ki iwọ ki o má ba kọ́ ìwa rẹ̀, iwọ a si gbà ikẹkùn fun ara rẹ.

26 Máṣe wà ninu awọn ti nṣe igbọwọ, tabi ninu awọn ti o duro fun gbèse.

27 Bi iwọ kò ba ni nkan ti iwọ o fi san, nitori kini yio ṣe gbà ẹní rẹ kuro labẹ rẹ?

28 Máṣe yẹ̀ àla ilẹ igbàni, ti awọn baba rẹ ti pa.

29 Iwọ ri enia ti o nfi aiṣimẹlẹ ṣe iṣẹ rẹ̀? on o duro niwaju awọn ọba; on ki yio duro niwaju awọn enia lasan.

## ORI 23.

NIGBATI iwọ ba joko lati ba ijoye jẹun, kiyesi ẹniti o wà niwaju rẹ gidigidi.

2 Ki o si fi ọbẹ le ara rẹ li ọfun, bi iwọ ba iṣe okundùn enia.

3 Máṣe fẹ onjẹ-didùn rẹ̀: nitoripe onjẹ ẹ̀tan ni.

4 Máṣe lãla ati lọrọ̀: ṣiwọ kuro ninu imoye ara rẹ.

5 Iwọ o ha fi oju rẹ wò o? kì yio si si mọ, nitoriti ọrọ̀ hu iyẹ-apá fun ara rẹ̀ bi ìdi ti nfò li oju ọrun.

6 Máṣe jẹ onjẹ oloju buburu, bẽni ki o má si ṣe fẹ onjẹ-didùn rẹ̀.

7 Nitoripe bi o ti nṣiro li ọkàn rẹ̀, bẹ̃ li o ri: mã jẹ, ki o si ma mu li o nwi fun ọ; ṣugbọn ọkàn rẹ̀ kò pẹlu rẹ.

8 Okele ti iwọ jẹ ni iwọ o pọ̀ jade, iwọ a si sọ ọ̀rọ didùn rẹ nù.

9 Máṣe sọ̀rọ li eti aṣiwère: nitoriti yio gàn ọgbọ́n ọ̀rọ rẹ.

10 Máṣe ṣi àla atijọ; má si ṣe bọ sinu oko alaini-baba.

11 Nitoripe Olurapada wọn lagbara; yio gbà ìja wọn ja ti awọn tirẹ.

12 Fi aiya si ẹkọ́, ati eti rẹ si ọ̀rọ ìmọ.

13 Máṣe fà ọwọ ibawi sẹhin kuro lara ọmọde, nitoripe bi iwọ ba fi paṣan nà a, on kì yio kú.

14 Iwọ fi paṣan nà a, iwọ o si gbà ọkàn rẹ̀ la kuro li ọrun-apadi.

15 Ọmọ mi, bi ọkàn rẹ ba gbọ́n, ọkàn mi yio yọ̀, ani emi pẹlu.

16 Inu mi yio si dún nigbati ètè rẹ ba nsọ̀rọ titọ.

17 Máṣe jẹ ki aiya rẹ ki o ṣe ilara si awọn ẹlẹṣẹ, ṣugbọn ki iwọ ki o wà ni ibẹ̀ru Oluwa, li ọjọ gbogbo.

18 Nitoripe ikẹhin mbẹ nitõtọ; ireti rẹ kì yio si ke kuro.

19 Gbọ́, iwọ ọmọ mi, ki iwọ ki o si gbọ́n, ki iwọ ki o si ma tọ́ aiya rẹ si ọ̀na titọ.

Digitized by Google

20 Máṣe wà ninu awọn ọmuti; ninu
awọn ti mba ẹran-ara awọn tikarawọn jẹ.
21 Nitoripe ọmuti ati ọjẹun ni yio di
talaka; ọlẹ ni yio si fi akisa bò ara rẹ̀.
22 Fetisi ti baba rẹ ti o bi ọ, má si ṣe
gàn iya rẹ, nigbati o ba gbó.
23 Ra otitọ, ki o má si ṣe tà a; ọgbọ́n
pẹlu ati ẹkọ́, ati imoye.
24 Baba olododo ni yio yọ̀ gidigidi:
ẹniti o si bi ọmọ ọlọgbọ́n, yio ni ayọ̀ ninu
rẹ̀.
25 Baba rẹ ati iya rẹ yio yọ̀, inu ẹniti o
bi ọ yio dùn.
26 Ọmọ mi, fi aiya rẹ fun mi, ki o si jẹ
ki oju rẹ ki o ni inu-didùn si ọ̀na mi.
27 Nitoripe agbere, iho jijin ni; ati ajeji
obirin, iho hiha ni.
28 On a si ba ni ibuba bi ole, a si sọ
awọn olurekọja di pupọ ninu awọn enia.
29 Tali o ni òṣi? tali o ni ibinujẹ? tali
o ni ijà? tali o ni asọ̀? tali o ni ọgbẹ lai-
nidi, tali o ni oju pipọn.
30 Awọn ti o duro pẹ nibi ọti-waini;
awọn ti nlọ idan ọti-waini àdalu wò.
31 Iwọ máṣe wò ọti-waini pe o pọn,
nigbati o ba fi àwọ rẹ̀ han ninu ago, ti a
ngbe e mì, ti o ndùn.
32 Nikẹhin on a buniṣán bi ejò, a si
bunijẹ bi paramọlẹ.
33 Oju rẹ yio wò awọn ajeji obirin, aiya
rẹ yio si sọ̀rọ ayidayida.
34 Nitõtọ, iwọ o dabi ẹniti o dubulẹ li
arin okun, tabi ẹniti o dubulẹ lòke òpó-
ọkọ̀.
35 Iwọ o si wipe, nwọn lù mi; kò dùn
mi; nwọn lù mi, emi kò si mọ̀: nigbawo
li emi o ji? emi o tun ma wá a kiri.

## ORI 24.

IWỌ máṣe ilara si awọn enia buburu, bẽni
ki o má si ṣe fẹ lati ba wọn gbe.
2 Nitoriti aiya wọn ngbiro iparun, ète
wọn si nsọ̀rọ ìwa-ika.
3 Ọgbọ́n li a fi ikọ ile; oye li a si fi ifi
idi rẹ̀ kalẹ.
4 Nipa ìmọ ni iyará fi ikún fun oniruru
ọrọ̀ iyebiye ati didùn.
5 Ọlọgbọ́n enia li agbara: nitõtọ enia
ìmọ a sọ agbara rẹ̀ di pupọ.
6 Nitori nipa ìgbimọ ọgbọ́n ni iwọ o fi
ṣigun rẹ: ati ninu ọ̀pọlọpọ ìgbimọ ni iṣẹ-
gun.
7 Ọgbọ́n ga jù aṣiwère lọ: on kì yio yà
ẹnu rẹ̀ ni ẹnu-bode.
8 Ẹniti nhùmọ ati ṣe ibi li a o pè li enia
ìwa-ika.
9 Ironu wère li ẹ̀ṣẹ; irira ninu enia si li
ẹlẹgàn.
10 Bi iwọ ba rẹwẹsi li ọjọ ipọnju, agbara
rẹ kọ to nkan.
11 Bi iwọ ba fà sẹhin ati gbà awọn ti a
wọ́ lọ sinu ikú, ati awọn ti a yàn fun pipa.
12 Ti iwọ si wipe, wò o, awa kò mọ̀ ọ;
kò ha jẹ pe ẹniti ndiwọ̀n ọkàn nkiyesi i?
ati ẹniti npa ọkàn rẹ mọ́, on li o mọ̀, yio si
san a fun enia gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀.
13 Ọmọ mi, jẹ oyin, nitoriti o dara; ati
afara oyin, ti o dùn li ẹnu rẹ:
14 Bẹ̃ni ìmọ ọgbọ́n yio ri si ọkàn rẹ: bi
iwọ ba ri i, nigbana ni ère yio wà, a kì yio
si ke ireti rẹ kuro.
15 Máṣe ba ni ibuba bi enia buburu, lati
gba ibujoko olododo: máṣe fi ibi isimi rẹ̀
ṣe ijẹ.
16 Nitoripe olõtọ a ṣubu nigba meje, a
si tun dide: ṣugbọn enia buburu yio ṣubu
sinu ibi.
17 Máṣe yọ̀ nigbati ọta rẹ ba ṣubu, má
si ṣe jẹ ki inu rẹ ki o dùn nigbati o ba
kọsẹ̀:
18 Ki Oluwa ki o má ba ri i, ki o si buru
li oju rẹ̀, on a si yi ibinu rẹ̀ pada kuro lori
rẹ̀.
19 Máṣe ilara si awọn enia buburu, má
si ṣe jowu enia buburu.
20 Nitoripe, ère kì yio si fun enia ibi;
fitila enia buburu li a o pa.
21 Ọmọ mi, iwọ bẹ̀ru Oluwa ati ọba: ki
iwọ ki o má si ṣe dàpọ mọ awọn ti nṣe
ayidayida.
22 Nitoripe wàhala wọn yio dide lojiji,
ati iparun awọn mejeji, tali o mọ̀ ọ!
23 Wọnyi pẹlu ni ọ̀rọ awọn ọlọgbọ́n.
Kò dara lati ṣe ojusaju ni idajọ.
24 Ẹniti o ba wi fun enia buburu pe,
olododo ni iwọ; on ni awọn enia yio bú,
awọn orilẹ-ède yio si korira rẹ̀.
25 Ṣugbọn awọn ti o ba a wi ni yio ni
inu-didùn, ibukún rere yio si bọ̀ sori wọn.
26 Yio dabi ẹniti o ṣe ifẹnukonu: ẹniti
o ba ṣe idahùn rere.
27 Mura iṣẹ rẹ silẹ lode, ki o si fi itara
tulẹ li oko rẹ; nikẹhin eyi, ki o si kọ́ ile
rẹ.
28 Máṣe ẹlẹri si ẹnikeji rẹ lainidi: ki
iwọ ki o má si ṣe fi ète rẹ ṣẹtan.
29 Máṣe wipe, bẹ̃li emi o ṣe si i, gẹgẹ bi
o ti ṣe si mi: emi o san a fun ọkọnrin na
gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀.
30 Mo kọja lọ li oko ọlẹ, ati lẹba ọgbà-
ajara ẹniti oye kù fun:
31 Si kiyesi i, ẹgún kún bo gbogbo rẹ̀,

Digitized by Google

ẹgún iwèpe si bo oju rẹ̀, iganna okuta rẹ̀ si
wo lulẹ.
32 Nigbana ni mo ri, mo si fi ọkàn mi
si i gidigidi: mo wò o, mo si gbà ẹkọ́.
33 Orun diẹ si i, õgbe diẹ, ikawọkòpọ
lati sùn diẹ.
34 Bẽli òṣi rẹ yio de bi ẹniti nrìn; ati
aini rẹ bi ọkọnrin ti o hamọra ogun.

## ORI 25.

WỌNYI pẹlu li owe Solomoni, ti awọn
ọkọnrin Hesekiah, ọba Juda kọ
silẹ.
2 Ogo Ọlọrun ni lati pa ọ̀ran mọ́: ṣu-
gbọ̀n ọlá awọn ọba ni lati wadi ọ̀ran.
3 Ọrun fun giga, ati ilẹ fun jijin bẽni a
kò le iwadi aiya awọn ọba.
4 Mu idarọ kuro ninu fadaka, ohun-elo
yio si jade fun alagbẹdẹ fadaka.
5 Mu enia buburu kuro niwaju ọba, a o
si fi idi itẹ́ rẹ̀ kalẹ ninu ododo.
6 Máṣe ṣefefe niwaju ọba, má si ṣe duro
ni ipò awọn enia nla.
7 Nitoripe, o san ki a wi fun ọ pe, wá
soke nihin, jù ki a fà ọ tì sẹhin niwaju
ọmọ-alade ti oju rẹ ti ri.
8 Máṣe jade lọ kankan lati jà, ki iwọ ki
o má ba ṣe alaimọ̀ eyiti iwọ o ṣe li opin rẹ̀,
nigbati aladugbo rẹ yio dojutì ọ.
9 Ba ẹnikeji rẹ ja ìja rẹ̀; ṣugbọn aṣiri
ẹlomiran ni iwọ kò gbọdọ fihàn.
10 Ki ẹniti o ba gbọ́ ki o má ba dojuti
ọ, ẹ̀gan rẹ kì yio si lọ kuro lai.
11 Bi eso igi wura ninu agbọ̀n fadaka,
bẽni ọ̀rọ ti a sọ li akoko rẹ̀.
12 Bi oruka wura ati ohun ọṣọ́ wura
daradara, bẽli ọlọgbọ́n olubaniwi li eti
igbọràn.
13 Bi otutu òjo-didì ni ìgba ikore, bẽni
olõtọ ikọ̀ si awọn ti o rán a: nitoriti o tù
awọn oluwa rẹ̀ ninu.
14 Ẹnikẹni ti o ba ṣefefe ninu ẹ̀bun ẹ̀tan,
o dabi awọsanma ati afẹfẹ ti kò ni òjo.
15 Ipamọra pipẹ li a fi iyi ọmọ-alade li
ọkàn pada, ahọn ti o kunna ni ifọ egungun.
16 Bi iwọ ba ri oyin, jẹ eyi ti o to fun ọ,
ki o má ba su ọ, iwọ a si bì i.
17 Fà ẹsẹ sẹhin kuro ni ile aladugbo
rẹ; ki agara rẹ o má ba da a, on a si
korira rẹ.
18 Ẹniti o jẹri eke si ẹnikeji rẹ̀, ni olu-
gboro, ati idà, ati ọfà mimu.
19 Igbẹkẹle alaiṣõtọ enia ni ìgba ipọnju,
o dabi ehin ti o ṣẹ́, ati ẹsẹ̀ ti o yẹ̀ lori ike.
20 Bi ẹniti o bọ aṣọ nigba otutu, ati bi
ọti-kikan ninu õru, bẽli ẹniti nkọrin fun
ẹniti inu rẹ̀ bajẹ.
21 Bi ebi ba npa ọta rẹ, fun u li onjẹ; bi
ongbẹ ba si gbẹ ẹ, fun u li ohun mimu.
22 Nitoriti iwọ o kó ẹyin iná jọ si ori
rẹ̀, Oluwa yio san fun ọ.
23 Afẹfẹ ariwa mu òjo wá, bẽli ahọn
isọ̀rọ-ẹni-lẹhin imu oju kikoro wá.
24 O san lati joko ni igun òke àja, jù
pẹlu onija obirin lọ ninu ile ajumọgbe.
25 Bi omi tutu si ọkàn ti ongbẹ ngbẹ,
bẽni ihin-rere lati ilu okere wá.
26 Olododo ti o ṣipo pada niwaju enia
buburu, o dabi orisun ti o wú, ati isun-omi
ti o bajẹ.
27 Kò dara lati jẹ oyin pupọ: bẽni lati
ma wadi ọ̀ran wuwo, o wuwo.
28 Ẹniti kò le ṣe akoso ara rẹ̀, o dabi ilu
ti a wo lulẹ, ti kò si li odi.

## ORI 26.

BI òjo-didì ni ìgba ẹrun, ati bi òjo ni
ìgba ikore, bẽli ọlá kò yẹ fun aṣiwère.
2 Bi ẹiyẹ fun iṣikiri, ati alapandẹdẹ fun
fifò, bẽni egún kì yio wá lainidi.
3 Lagbà fun ẹṣin, ijanu fun kẹtẹkẹtẹ,
ati ọgọ fun ẹhin aṣiwère.
4 Máṣe da aṣiwère lohùn gẹgẹ bi wère
rẹ̀, ki iwọ pãpa ki o má ba dabi rẹ̀.
5 Da aṣiwère lohùn gẹgẹ bi wère rẹ̀, ki
on ki o má ba gbọ́n li oju ara rẹ̀.
6 Ẹniti o rán iṣẹ nipa ọwọ aṣiwère, o ke
ẹsẹ ara rẹ̀ kuro, o si jẹ ara rẹ̀ niya.
7 Bi ẹsẹ mejeji ti rọ̀ silẹ lara amọkun,
bẽli owe li ẹnu awọn aṣiwère.
8 Bi ẹniti o fi àpo okuta iyebiye sinu
okiti okuta, bẽli ẹniti nfi ọlá fun aṣiwère.
9 Bi ẹgún ti igún ọmuti lọwọ, bẽli owe
li ẹnu awọn aṣiwère.
10 Bi tafatafa ti o mu gbogbo enia gbọ-
gbẹ, bẽni ẹniti o gbà aṣiwère si iṣẹ, ti o si
gba awọn olurekọja si iṣẹ-owo.
11 Bi aja ti ipada sinu ẽbì rẹ̀, bẽli aṣi-
wère itun pada sinu wère rẹ̀.
12 Iwọ ri ẹnikan ti o gbọ́n li oju ara rẹ̀?
ireti mbẹ fun aṣiwère jù fun u lọ.
13 Ọlẹ enia wipe, Kiniun mbẹ li ọ̀na;
kiniun mbẹ ni igboro.
14 Bi ilẹkun ti iyi lori ìwakun rẹ̀, bẽli
ọlẹ lori ẹní rẹ̀.
15 Ọlẹ pa ọwọ rẹ̀ mọ́ sinu iṣãsun; kò si
le yọ ọ jade pada wá si ẹnu rẹ̀.
16 Ọlẹ gbọ́n li oju ara rẹ̀ jù enia meje lọ
ti nwọn le fi ọgbọ́n dahùn ọ̀ran.
17 Ẹniti nkọja lọ, ti o si dasi ìja ti kì
iṣe tirẹ̀, o dabi ẹniti o mu ajá leti.

Digitized by Google

18 Bi asiwin ti nsọ ọ̀kọ, ọfa, ati ikú,
19 Bẹ̃li ẹniti o tan ẹnikeji rẹ̀ jẹ, ti o si
wipe, Iré ha kọ li emi nṣe ?
20 Nigbati igi tan, ina a kú, bẹ̃ni nigbati
olofofo kò si, ìja a da.
21 Bi ẹyin ti ri si ẹyin-iná, ati igi si
iná ; bẹ̃li enia onijà lati da ìja silẹ.
22 Ọ̀rọ olofofo dabi adindùn, nwọn a si
wọ isalẹ inu lọ.
23 Ete jijoni, ati aiya buburu, dabi
idarọ fadaka ti a fi bò ìkoko.
24 Ẹniti o ba korira, ti o fi ète rẹ̀ ṣe
agabagebe, yio si pa ẹ̀tan mọ́ ninu rẹ̀.
25 Nigbati o ba sọ̀rọ daradara, máṣe gbà
a gbọ́: nitoripe irira meje li o wà li aiya
rẹ̀,
26 Ẹniti a fi ẹ̀tan bò irira rẹ̀ mọlẹ, ìwa-
buburu rẹ̀ li a o fi hàn niwaju gbogbo ijọ :
27 Ẹnikẹni ti o ba wà ihò yio ṣubu sinu
rẹ̀ : ẹniti o ba si nyi okuta, on ni yio pada
tọ̀.
28 Ahọn eke korira awọn ti a fi njẹniya;
ẹnu ipọnni a si ma ṣiṣẹ iparun.

ORI 27.

MAṢE leri ara rẹ niti ọjọ ọla, nitoriti
iwọ kò mọ̀ ohun ti ọjọ kan yio hù
jade.
2 Jẹ ki ẹlomiran ki o yìn ọ, ki o máṣe
ẹnu ara rẹ ; alejo, ki o má si ṣe ète ara rẹ.
3 Okuta wuwo, yanrin si wuwo, ṣugbọn
ibinu aṣiwère, o wuwo jù mejeji lọ.
4 Ibinu ni ìka, irunu si ni kikún-omi ;
ṣugbọn tani yio duro niwaju owú.
5 Ibawi nigbangba, o san jù ifẹ ti o fara-
sin lọ.
6 Otitọ li ọgbẹ ọrẹ́: ṣugbọn ifẹnukonu
ọta li ẹ̀tan.
7 Ọkàn ti o yó fi ẹsẹ tẹ afara-oyin ;
ṣugbọn ọkàn ti ebi npa, ohun kikoro
gbogbo li o dùn.
8 Bi ẹiyẹ ti ima fò kiri lati inu itẹ́ rẹ̀,
bẹ̃li enia ti o nrìn kiri jina si ipò rẹ̀.
9 Ororo ati turari mu ọkàn dùn : bẹ̃ni
adùn ọrẹ ẹni nipa ìgbimọ atọkànwa.
10 Ọrẹ́ rẹ ati ọrẹ́ baba rẹ, máṣe kọ̀ silẹ,
bẹ̃ni ki iwọ ki o máṣe lọ si ile arakọnrin
li ọjọ idãmu rẹ: nitoripe aladugbo ti o
sunmọ ni, o san jù arakọnrin ti o jina
rere lọ.
11 Ọmọ mi, ki iwọ ki o gbọ́n, ki o si
mu inu mi dùn ; ki emi ki o le da ẹniti
ngàn mi lohùn.
12 Amoye enia ri ibi tẹlẹ, o si pa ara
rẹ̀ mọ́ ; ṣugbọn awọn òpe kọja a si jẹ wọn
niya.
13 Gbà aṣọ rẹ̀ nitoriti o ṣe onigbọwọ
alejo, si gbà ohun ẹri lọwọ rẹ̀ fun ajeji
obirin.
14 Ẹniti o ba ndide ni kutukutu ti o
nfi ohùn rara kí ọrẹ́ rẹ̀, egún li a o kà a si
fun u.
15 Ọṣọrọ-òjo li ọjọ òjo, ati onija obirin,
bakanna ni.
16 Ẹnikẹni ti o pa a mọ́, o pa ẹfũfu mọ́,
ororo ọwọ-ọtún rẹ̀ yio si fihàn.
17 Irin a ma pọn irin : bẹ̃li ọkọnrin
ipọn oju ọrẹ́ rẹ̀.
18 Ẹnikẹni ti o tọju igi-ọpọtọ yio jẹ eso
rẹ̀ ; bẹ̃li ẹniti o duro ti oluwa rẹ̀ li a o
buyìn fun.
19 Bi oju ti ikò oju li omi, bẹ̃li aiya
enia si enia.
20 Ipò-okú ati iparun kì ikún, bẹ̃ni kì
isu oju enia.
21 Bi koro fun fadaka, ati ileru fun
wura, bẹ̃li enia si iyìn rẹ̀.
22 Bi iwọ tilẹ fi ọmọri-odó gún aṣiwère
ninu odo larin alikama, wère rẹ̀ kì yio fi
i silẹ.
23 Iwọ ma ṣaniyan ati mọ̀ ìwa agbo-ẹran
rẹ, ki iwọ ki o si bojuto awọn ọwọ́-ẹran rẹ.
24 Nitoripe ọrọ̀ ki iwà titi lai : ade a
ha si ma wà de irandiran ?
25 Koriko yọ, ati ọmunú koriko fi ara
hàn, ati ewebẹ̀ awọn òke kojọ pọ̀.
26 Awọn ọdọ-agutan ni fun aṣọ rẹ, awọn
obukọ si ni iye-owo oko.
27 Iwọ o si ni wàra ewurẹ to fun onjẹ
rẹ, fun onjẹ awọn ara ile rẹ, ati fun onjẹ
awọn iranṣẹ-birin rẹ.

ORI 28

ENIA buburu sá nigbati ẹnikan kò le e :
ṣugbọn olododo laiya bi kiniun.
2 Nipa irekọja ilẹ li awọn ijoye idi
pupọ, ṣugbọn nipa amoye ati oni ìmọ̀ enia
kan, li a mu ilẹ pẹ.
3 Olupọnju ti o nni olupọnju lara, o
dabi agbalọ òjo ti kò fi onjẹ silẹ.
4 Awọn ti o kọ̀ ofin silẹ a ma yìn enia
buburu : ṣugbọn awọn ti o pa ofin mọ́ a
ma binu si wọn.
5 Oye idajọ kò ye enia buburu : ṣu-
gbọn awọn ti nṣe afẹri Oluwa moye ohun
gbogbo.
6 Talaka ti nrin ninu iduro-ṣinṣin rẹ̀,
o san jù alarekereke ìwa, bi o tilẹ ṣe ọlọrọ̀.
7 Ẹnikẹni ti o pa ofin mọ́, o ṣe ọlọgbọ́n
ọmọ : ṣugbọn ẹniti o ṣe ẹlẹgbẹ jẹgudura-
gudu, o tì baba rẹ̀ li oju.
8 Ẹniti o fi elé ati èrè aiṣõtọ sọ ọrọ̀ rẹ̀



Digitized by Google

di pupọ, o kó o jọ fun ẹniti yio ṣãnu fun
awọn talaka.
9 Ẹniti o mu eti rẹ̀ kuro lati gbọ́ ofin,
ani adura rẹ̀ pãpa yio di irira.
10 Ẹnikẹni ti o mu olododo ṣìna si ọ̀na
buburu, ontikararẹ̀ yio bọ si iho, ṣugbọn
aduro-ṣinṣin yio jogun ohun rere.
11 Ọlọrọ̀ gbọ́n li oju ara rẹ̀: ṣugbọn
talaka ti o moye ridi rẹ̀.
12 Nigbati awọn olododo enia ba nyọ̀,
ọṣọ́ nla a wà; ṣugbọn nigbati enia buburu
ba dide, enia a sá pamọ́.
13 Ẹniti o bo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọlẹ kì yio ṣe rere:
ṣugbọn ẹnikẹni ti o jẹwọ ti o si kọ̀ ọ silẹ
yio ri ãnu.
14 Ibukún ni fun ẹniti o bẹ̀ru nigba-
gbogbo: ṣugbọn ẹniti o ba sé aiya rẹ̀ le ni
yio ṣubu sinu ibi.
15 Bi kiniun ti nke ramùramu, ati
ẹranko beari ti nfi ebi sare kiri; bẹ̃ni ẹni
buburu ti o joye lori awọn talaka.
16 Ọmọ-alade ti o ṣe alaimoye pupọ ni
iṣe ìwa-ika pupọ pẹlu: ṣugbọn eyiti o
korira ojukokoro yio mu ọjọ rẹ̀ pẹ.
17 Enia ti o ba hù ìwa-ika si ẹ̀jẹ ẹnikeji,
yio sá lọ si ihò: ki ẹnikan ki o máṣe mu u.
18 Ẹnikẹni ti o ba nrin dẽde ni yio là:
ṣugbọn ẹniti o nfi ayidayida rìn loju ọ̀na
meji, yio ṣubu ninu ọkan ninu wọn.
19 Ẹniti o ba ro ilẹ rẹ̀ yio li ọ̀pọ onjẹ:
ṣugbọn ẹniti o ba ntọ̀ enia asan lẹhin yio
ni ọ̀ṣi to.
20 Olõtọ enia yio pọ̀ fun ibukún: ṣu-
gbọn ẹniti o kanju ati là kì yio ṣe alaijiya.
21 Iṣojusaju enia kò dara: nitoripe fun
òkele onjẹ kan, ọkọnrin na yio ṣẹ̀.
22 Ẹniti o kanju ati là, o li oju ilara,
kò si rò pe ọ̀ṣi mbọ̀wá ta on.
23 Ẹniti o ba enia wi yio ri ojurere ni
ikẹhin jù ẹniti nfi ahọn pọn ọ lọ.
24 Ẹnikẹni ti o ba nja baba tabi iya rẹ̀
li ole, ti o si wipe, kì iṣe ẹ̀ṣẹ; on na li
ẹgbẹ apanirun.
25 Ẹniti o ṣe agberaga li aiya, a rú ìja
soke, ṣugbọn ẹniti o gbẹkẹ rẹ̀ le Oluwa li
a o mu sanra.
26 Ẹniti o gbẹkẹ le aiya ara rẹ̀, aṣiwère
ni; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba nfi ọgbọ́n rìn,
on li a o gbà la.
27 Ẹniti o ba nfi fun olupọnju kì yio
ṣe alaini; ṣugbọn ẹniti o mu oju rẹ̀ kuro,
yio gbà egún pupọ.
28 Nigbati enia buburu ba hù, awọn
enia a sá pamọ́: ṣugbọn nigbati nwọn ba
ṣegbe, awọn olododo a ma pọ̀ si i.

ORI 29.

ẸNITI a ba mbawi ti o wà ọrùn kì, yio
parun lojiji, laisi atunṣe.
2 Nigbati awọn olododo wà lori oyè,
awọn enia a yọ̀; ṣugbọn nigbati enia
buburu ba gori oyè, awọn enia a kẹdùn.
3 Ẹnikẹni ti o fẹ ọgbọ́n, a mu baba rẹ̀
yọ̀: ṣugbọn ẹniti o mba panṣaga kẹgbẹ, a
ba ọrọ̀ rẹ̀ jẹ.
4 Nipa idajọ li ọba imu ilẹ tòro; ṣugbọn
ẹniti o ba ngbà ọrẹ a bì i ṣubu.
5 Ẹniti o npọ́n ẹnikeji rẹ̀, ta àwọn silẹ
fun ẹsẹ rẹ̀.
6 Ninu irekọja enia ibi, ikẹkùn mbẹ:
ṣugbọn olododo a ma kọrin, a si ma yọ̀.
7 Olododo a ma rò ọ̀ran talaka: ṣugbọn
enia buburu kò ṣú si i lati rò o.
8 Awọn ẹlẹgàn enia da irukerudo si ilu:
ṣugbọn awọn ọlọgbọ́n enia ṣẹ́ri ibinu kuro.
9 Ọlọgbọ́n enia ti mba aṣiwère enia ja,
bi inu li o mbi, bi ẹrín li o nrín, isimi
kò si.
10 Awọn enia-ẹ̀jẹ korira aduro-ṣinṣin:
ṣugbọn awọn olododo a ma ṣe afẹri ọkàn rẹ̀.
11 Aṣiwère a sọ gbogbo inu rẹ̀ jade:
ṣugbọn ọlọgbọ́n a pa a mọ́ di ìgba ikẹhin.
12 Bi ijoye ba feti si ọ̀rọ-eke, gbogbo
awọn iranṣẹ rẹ̀ ni yio buru.
13 Talaka ati aninilara enia pejọ pọ̀:
Oluwa li o ntan imọlẹ si oju awọn mejeji.
14 Ọba ti o fi otitọ ṣe idajọ talaka, itẹ́
rẹ̀ yio fi idi mulẹ lailai.
15 Paṣan ati ibawi funni li ọgbọ́n:
ṣugbọn ọmọ ti a ba jọwọ rẹ̀ fun ara rẹ̀, a
dojuti iya rẹ̀.
16 Nigbati awọn enia buburu ba npọ̀ si
i, irekọja a pọ̀ si i: ṣugbọn awọn olododo
yio ri iṣubu wọn.
17 Tọ́ ọmọ rẹ, yio si fun ọ ni isimi; yio
si fi inu-didùn si ọ li ọkàn.
18 Nibiti iran-woli kò si, enia a yapa,
ṣugbọn ibukún ni fun ẹniti o pa ofin mọ́.
19 A kì ifi ọ̀rọ kilọ fun ọmọ-ọdọ; bi o
tilẹ ye e kì yio dahùn.
20 Iwọ ri enia ti o yara li ọ̀rọ rẹ̀? ireti
mbẹ fun aṣiwère jù fun u lọ.
21 Ẹniti o ba fi ikẹ́ tọ́ ọmọ-ọdọ rẹ̀ lati
igba-ewe wá, yio jẹ ọmọ nikẹhin rẹ̀.
22 Ẹni ibinu ru ìja soke, ati ẹni ikannu
pọ̀ ni irekọja.
23 Igberaga enia ni yio rẹ̀ ẹ silẹ: ṣugbọn
onirẹlẹ ọkàn ni yio gbà ọlá.
24 Ẹniti o kó ẹgbẹ ole korira ọkàn ara
rẹ̀: o ngbọ́ ifiré, kò si fihan.
25 Ibẹ̀ru enia ni imu ikẹkùn wá: ṣugbọn

Digitized by Google

ẹnikẹni ti o gbẹkẹ rẹ̀ le Oluwa li a o gbe
leke.
26 Ọpọlọpọ enia li o nwá ojurere ijoye:
ṣugbọn idajọ enia li o nti ọdọ Oluwa wá.
27 Alaiṣõtọ enia, irira ni si awọn olo-
dodo: ẹniti o si ṣe aduroṣinṣin li ọ̀na,
irira ni si enia buburu.

## ORI 30.

ỌRỌ Aguri, ọmọ Jake, ọ̀rọ ẹkọ́ ti ọkọnrin
na ti sọ, fun Itieli, ani fun Itieli ati
Ukali.
2 Nitõtọ emi ṣiwère jù ẹlomiran lọ, emi
kò si ni imoye enia.
3 Emi kò tilẹ kọ́ ọgbọ́n, emi kò tilẹ ni
ìmọ ohun mimọ́.
4 Tali o ti gòke lọ si ọrun, tabi ti o si
sọkalẹ wá? tali o kó afẹfẹ jọ li ọwọ rẹ̀?
tali o di omi sinu aṣọ; tali o fi gbogbo
opin aiye le ilẹ? Orukọ rẹ̀ ti ijẹ, ati orukọ
ọmọ rẹ̀ ti ijẹ, bi iwọ ba le mọ̀ ọ?
5 Gbogbo ọ̀rọ Oluwa ni funfun: on
li asà fun gbogbo awọn ti o gbẹkẹ wọn
le e.
6 Iwọ máṣe fi kún ọ̀rọ rẹ̀, ki on má ba
ba ọ wi, a si mu ọ li eke.
7 Ohun meji ni mo tọrọ lọdọ rẹ; máṣe
fi wọn dù mi ki emi to kú.
8 Mu asan ati eke jina si mi: máṣe fun
mi li òṣi, máṣe fun mi li ọrọ̀; fi onjẹ ti o
to fun mi bọ mi.
9 Ki emi ki o má ba yó jù, ki emi ki o
má si sẹ́ ọ, pe ta li Oluwa? tabi ki emi má
ba tòṣi, ki emi si jale, ki emi si ṣẹ̀ si orukọ
Ọlọrun mi.
10 Máṣe fi iranṣẹ sùn oluwa rẹ̀, ki o má
ba fi ọ bu, ki iwọ má ba jẹbi.
11 Iran kan wà ti nfi baba rẹ̀ bu, ti kò
si sure fun iya rẹ̀.
12 Iran kan wà, ti o mọ́ li oju ara rẹ̀,
ṣugbọn a kò ti iwẹ̀ ẹ nù kuro ninu ẽri
rẹ̀.
13 Iran kan wà, yẽ, oju rẹ̀ ti gbega to!
ipenpeju rẹ̀ si gbé soke.
14 Iran kan wà, ehin ẹniti o dabi idà,
erigi rẹ̀ dabi ọbẹ, lati jẹ talaka run kuro
lori ilẹ, ati awọn alaini kuro ninu awọn
enia.
15 Eṣúṣu ni ọmọbirin meji, ti nkigbe
pe, Muwá, muwá. Ohun mẹta ni mbẹ ti
a kò le tẹ lọrùn lai, ani mẹrin kì iwipe,
o to.
16 Isa-okú, ati inu àgan; ilẹ ti kì ikún
fun omi; ati iná ti kì iwipe, o to.
17 Oju ti o sin baba rẹ̀ jẹ, ti o gàn ati
gbọ́ ti iya rẹ̀, kanakáná ẹba odò ni yio yọ
ọ jade, ọmọ idì a si mu u jẹ.
18 Ohun mẹta ni mbẹ ti o ṣe iyanu fun
mi, nitõtọ, mẹrin li emi kò mọ̀.
19 Ipa idì loju ọrun; ipa ejò lori apata:
ipa ọkọ̀ loju okun; ati ìwa ọkọnrin pẹlu
wundia.
20 Bẹ̃ni ìwa agbere obirin: o jẹun, o si
nù ẹnu rẹ̀ nù, o si wipe, emi kò ṣe buburu
kan.
21 Nitori ohun mẹta, aiye a di rũru, ati
labẹ mẹrin ni kò le duro.
22 Iranṣẹ, nigbati o jọba; ati aṣiwère,
nigbati o yo fun onjẹ;
23 Fun obirin, ti a korira, nigbati a sọ
ọ di iyale; ati fun iranṣẹbirin, nigbati o di
arole iya rẹ̀.
24 Ohun mẹrin ni mbẹ ti o kerejù lori
ilẹ, sibẹ nwọn gbọ́n, nwọn kọ́ni li ẹkọ́.
25 Alailagbara enia li ẽra, ṣugbọn nwọn
a pese onjẹ wọn silẹ ni ìgba ẹ̀run.
26 Alailagbara enia li ehoro, ṣugbọn
nwọn a ṣe ìho wọn ni palapala okuta.
27 Awọn ẽṣú kò li ọba, sibẹ gbogbo wọn
a jade lọ li ọwọ́-ọwọ́;
28 Ọmọle fi ọwọ rẹ̀ dì mu, o si wà li ãfin
awọn ọba.
29 Ohun mẹta ni mbẹ ti nrìn rere, nitõ-
tọ, mẹrin li o daradara ni ìrin rirìn:
30 Kiniun ti o lagbara julọ ninu ẹranko,
ti kò si pẹhinda fun ẹnikan;
31 Ẹṣin ti a dì lẹgbẹ; ati obukọ; ati
ọba larin awọn enia rẹ̀.
32 Bi iwọ ba ti ṣiwère ni gbigbe ara rẹ
soke, tabi bi iwọ ba ti ròmu ibi, fi ọwọ rẹ
le ẹnu rẹ.
33 Nitõtọ, mimì wàra ni imu ori-amọ
wá, ati fifun imu ni imu ẹ̀jẹ jade; bẹ̃ni
riru ibinu soke ni imu ìja wá.

## ORI 31.

ỌRỌ Lemueli, ọba, ọ̀rọ-ẹkọ́ ti ìya rẹ̀
kọ́ ọ.
2 Kini, ọmọ mi? ki si ni, ọmọ inu mi?
ati kini, ọmọ ẹ̀jẹ́ mi?
3 Máṣe fi agbara rẹ fun awọn obirin,
tabi ìwa rẹ fun awọn obirin ti mbà awọn
ọba jẹ.
4 Kì iṣe fun awọn ọba, Lemueli, kì iṣe
fun awọn ọba lati mu ọti-waini; bẹ̃ni kì
iṣe fun awọn ọmọ alade lati fẹ ọti lile:
5 Ki nwọn ki o má ba mu, nwọn a
si gbagbe ofin, nwọn a si yi idajọ awọn
olupọnju.
6 Fi ọti lile fun ẹniti o mura tan lati
ṣegbe, ati ọti-waini fun awọn oninu bibajẹ.

Digitized by Google

7 Jẹ ki o mu, ki o si gbagbe aini rẹ̀, ki
o má si ranti òṣi rẹ̀ mọ́.
8 Yà ẹnu rẹ fun ayadi, ninu ọ̀ran gbogbo
ẹniti iṣe ọmọ iparun.
9 Yà ẹnu rẹ, fi ododo ṣe idajọ, ki o si
gbèja talaka ati alaini.
10 Tani yio ri obirin oni iwa-rere? nito-
riti iye rẹ̀ kọja iyùn.
11 Aiya ọkọ rẹ̀ gbẹkẹle e laibẹ̀ru, bẽni
on kì yio ṣe alaini ère iṣẹ.
12 Rere li obirin na yio ma ṣe fun u, kì
iṣe buburu li ọjọ aiye rẹ̀ gbogbo.
13 Obirin na yio ma ṣafẹri kubusu ati
ọ̀gbọ, o si fi ọwọ rẹ̀ ṣiṣẹ tinutinu.
14 O dabi ọkọ̀ oniṣowo: o si mu onjẹ rẹ̀
lati ọ̀na jijin rére wá.
15 On a si dide nigbati ilẹ kò ti imọ́, a
si fi onjẹ fun enia ile rẹ̀, ati iṣẹ õjọ fun
awọn ọmọbirin rẹ̀.
16 O kiyesi oko, o si mu u: ère ọwọ rẹ̀
li o fi gbin ọgbà-ajara.
17 O fi agbara gbà ẹ̀gbẹ rẹ̀ li ọjá, o si mu
apa rẹ̀ mejeji le.
18 O kiyesi i pe ọjà on dara: fitila rẹ̀ kò
kú li oru.
19 O fi ọwọ rẹ̀ le kẹkẹ́-owú, ọwọ rẹ̀ si di
ìranwu mu.
20 O nà ọwọ rẹ̀ si talaka; nitõtọ, ọwọ
rẹ̀ si kàn alaini.
21 On kò si bẹ̀ru ò̀jo-didì fun awọn ara
ile rẹ̀; nitoripé gbogbo awọn ara ile rẹ̀ li a
wọ̀ li aṣọ iṣẹpo meji.
22 On si wun aṣọ titẹ́ fun ara rẹ̀; ẹ̀wu
daradara ati elese aluko li aṣọ rẹ̀.
23 A mọ̀ ọkọ rẹ̀ li ẹnu-bode, nigbati o
ba joko pẹlu awọn àgba ilẹ na.
24 O da aṣọ ọ̀gbọ daradara, o si tà a,
pẹlupẹlu o fi ọjá amure fun oniṣòwo tà.
25 Agbara ati iyìn li aṣọ rẹ̀; on o si yọ̀
si ọjọ ti mbọ.
26 O fi ọgbọ́n yà ẹnu rẹ̀; ati li ahọn rẹ̀
li ofin iṣeun.
27 O fi oju silẹ wò ìwa awọn ara ile rẹ̀,
kò si jẹ onjẹ imẹlẹ.
28 Awọn ọmọ rẹ̀ dide, nwọn si pè e li
alabukúnfun, ati bãle rẹ̀ pẹlu, on si fi iyìn
fun u.
29 Ọpọlọpọ awọn ọmọbirin li o hùwa
rere, ṣugbọn iwọ ta gbogbo wọn yọ.
30 Oju daradara li ẹ̀tan, ẹwà si jasi asan:
ṣugbọn obirin ti o bẹ̀ru Oluwa, on ni ki a
fi iyìn fun.
31 Fi fun u ninu eso-iṣẹ ọwọ rẹ̀; jẹ ki
iṣẹ ọwọ ara rẹ̀ ki o si yìn i li ẹnu-bode.

# IWE ONIWASU.

## ORI 1.

ỌRỌ oniwasu, ọmọ Dafidi, ti o jọba ni
Jerusalemu.
2 Asan inu asan, oniwasu na wipe, asan
inu asan; gbogbo rẹ̀ asan ni!
3 Ere kili enia jẹ ninu gbogbo lãla rẹ̀ ti
o ṣe labẹ õrùn?
4 Iran kan lọ, iran miran si bọ̀: ṣugbọn
aiye duro titi lai.
5 Orùn pẹlu là, õrùn si wọ̀, o si yara lọ
si ipò rẹ̀ nibiti o ti là.
6 Afẹfẹ nfẹ lọ siha gusu, a si yipada siha
ariwa; o si nlọ sihin sọhun titi, afẹfẹ si
tun pada gẹgẹ nipa ayika rẹ̀.
7 Odò gbogbo ni nṣàn sinu okun; ṣu-
gbọn okun kò kún, nibiti awọn odò ti nṣàn
wá, nibẹ ni nwọn si tun pada lọ.
8 Ọ̀rọ gbogbo kò to; enia kò le sọ ọ:
iran kì isu oju, bẽli eti kì ikún fun gbi-
gbọ́.
9 Ohun ti o wà, on ni yio si wà; ati
eyiti a ti ṣe li eyi ti a o ṣe; kò si ohun
titun labẹ õrùn.
10 Ohun kan wà nipa eyi ti a wipe, Wò
o, titun li eyi! o ti wà na nigba atijọ, ti o
ti wà ṣaju wa.
11 Kò si iranti ohun iṣaju; bẽni iranti
kì yio si fun ohun ikẹhin ti mbọ̀, lọdọ awọn
ti mbọ̀ ni igba ikẹhin.
12 Emi oniwasu jọba lori Israeli ni
Jerusalemu.
13 Mo si fi aiya mi si ati ṣe afẹri on ati
wadi ọgbọ́n niti ohun gbogbo ti a nṣe labẹ
ọrun, lãla kikan yi li Ọlọrun fi fun awọn
ọmọ enia lati ṣe lãla ninu rẹ̀.
14 Mo ti ri iṣẹ gbogbo ti a nṣe labẹ

Digitized by Google

õrùn ; si kiyesi i, asan ni gbogbo rẹ̀ ati
imulẹmofo.
15 Eyi ti o wọ́, a kò le mu u tọ́ : ati iye
àbukun, a kò le kà a.
16 Mo si ba aiya ara mi sọ̀rọ wipe, kiye-
si i, mo li ọgbọ́n nla, mo si fi kún u jù
gbogbo wọn lọ ti o ti ṣaju mi ni Jerusale-
mu ; aiya mi si ri ohun pupọ nla niti
ọgbọ́n ati ti ìmọ.
17 Nigbati mo fi aiya mi si ati mọ̀
ọgbọ́n, ati lati mọ̀ isinwin ati iwère : ni-
gbana ni mo mọ̀ pe, eyi pẹlu jẹ imulẹmofo,
18 Nitoripe ninu ọgbọ́n pupọ ni ibinujẹ
pupọ wà, ẹniti o si nsọ ìmọ di pupọ, o nsọ
ikãnu di pupọ.

## ORI 2.

EMI wi ninu mi pe, wá na ! emi o fi iré-
ayọ̀ dan ọ wò, nitorina mã jẹ afẹ́ ! si
kiyesi i, asan li eyi pẹlu !
2 Emi wi fun ẹrin pe, Iwère ni ọ : ati
fun iré-ayọ̀ pe kili o nṣe ?
3 Mo rò ninu aiya mi lati fi ọti-waini
mu ara mi le, ṣugbọn emi nfi ọgbọ́n tọ́ aiya
mi : on ati fi ọwọ le iwère, titi emi o fi ri
ohun ti o dara fun ọmọ enia, ti nwọn iba
mã ṣe labẹ ọrun ni iye ọjọ aiye wọn gbogbo.
4 Mo ṣe iṣẹ nla fun ara mi ; mo kọ́ ile
pupọ fun ara mi ; mo gbin ọgbà-ajara fun
ara mi.
5 Mo ṣe ọgbà ati agbala daradara fun ara
mi, mo si gbin igi oniruru eso sinu wọn.
6 Mo ṣe adagun pupọ, lati ma bomi lati
inu wọn si igbo ti o nmu igi jade wá :
7 Mo ni iranṣẹ-kọnrin ati iranṣẹ-birin,
mo si ni ibile ; mo si ni ini agbo malu ati
agutan nlanla jù gbogbo awọn ti o wà ni
Jerusalemu ṣaju mi.
8 Mo si kó fadaka ati wura jọ ati iṣura
ti ọba ati ti igberiko, mo ni awọn olorin
ọkọnrin ati olorin obirin, ati didùn inu
ọmọ enia, aya ati obirin pupọ.
9 Bẽni mo tobi, mo si pọ̀ si i jù gbogbo
awọn ti o wà ṣaju mi ni Jerusalemu :
ọgbọ́n mi si mbẹ pẹlu mi.
10 Ohunkohun ti oju mi fẹ, emi kò pa a
mọ́ fun wọn ; emi kò si dù aiya mi li ohun
ayọ̀ kan ; nitoriti aiya mi yọ̀ ninu iṣẹ mi
gbogbo ; eyi si ni ipin mi lati inu gbogbo
lãla mi.
11 Nigbati mo wò gbogbo iṣẹ ti ọwọ mi
ṣe, ati lãla ti mo ṣe lãla lati ṣe : si kiyesi i,
asan ni gbogbo rẹ̀ ati imulẹmofo, ko si si
ère kan labẹ õrùn.
12 Mo si yi ara mi pada lati wò ọgbọ́n,
ati isinwin ati iwère : nitoripe kili ọkọnrin
na ti mbọ lẹhin ọba yio le ṣe ? eyi ti a ti ṣe
tan nigbani ni yio ṣe.
13 Nigbana ni mo ri pe ọgbọ́n ta wère
yọ, to iwọn bi imọlẹ ti ta òkunkun yọ.
14 Oju ọlọgbọ́n mbẹ li ori rẹ̀ ; ṣugbọn
aṣiwère nrìn li òkunkun : emitikalami si
mọ̀ pẹlu pe, eṣe kanna li o nṣe gbogbo wọn.
15 Nigbana ni mo wi li aiya mi pe, Bi o
ti nṣe si aṣiwère, bẽli o si nṣe si emitikala-
mi ; nitori kili emi si ṣe gbọ́n jù ? Nigba-
na ni mo wi li ọkàn mi pe, asan li eyi pẹlu.
16 Nitoripe iranti kò si fun ọlọgbọ́n
pẹlu aṣiwère lailai ; ki a wò o pe, bi akoko
ti o kọja, bẽli ọjọ ti mbọ̀, a o gbagbe gbo-
gbo rẹ̀. Ọlọgbọ́n ha ṣe nkú bi aṣiwère ?
17 Nitorina mo korira ìwa-laiye : nitori-
pe iṣẹ ti a ṣe labẹ õrun : ibi ni fun mi :
nitoripe asan ni gbogbo rẹ̀ ati imulẹmofo.
18 Nitõtọ mo korira gbogbo lãla mi ti
mo ṣe labẹ õrùn ; nitoriti emi o fi i silẹ fun
enia ti mbọ̀ lẹhin mi.
19 Tali o si mọ̀ bi ọlọgbọ́n ni yio ṣe tabi
aṣiwère ? sibẹ on ni yio ṣe olori iṣẹ mi gbo-
gbo ninu eyi ti mo ṣe lãla, ati ninu eyi ti
mo fi ara mi hàn li ọlọgbọ́n labẹ õrùn.
Asan li eyi pẹlu.
20 Nitorina mo kirilọ lati mu aiya mi ṣí
kuro ninu gbogbo lãla mi ti mo ṣe labẹ
õrùn.
21 Nitoriti enia kan mbẹ, iṣẹ ẹniti o wà
li ọgbọ́n ati ni ìmọ, ati ni iṣedẽde ; sibẹ
ẹniti kò ṣe lãla ninu rẹ̀ ni yio fi i silẹ fun
ni ipin rẹ̀. Eyi pẹlu asan ni ati ibi nlanla.
22 Nitoripe kili enia ni ninu gbogbo
lãla rẹ̀ ti o fi nṣe lãla labẹ õrùn ?
23 Nitoripe ọjọ rẹ̀ gbogbo, ikãnu ni, ati
iṣẹ rẹ̀, ibinujẹ, nitõtọ aiya rẹ̀ kò simi li
oru. Eyi pẹlu asan ni.
24 Kò si ohun ti o dara fun enia jù ki o
jẹ, ki o si mu ati ki o mu ọkàn rẹ̀ jadùn
ohun rere ninu lãla rẹ̀. Eyi ni mo ri pẹlu
pe, lati ọwọ Ọlọrun wá ni.
25 Nitoripe tali o le jẹun, tabi tani pẹlu
ti o le mọ̀ adùn jù mi lọ ?
26 Nitoripe Ọlọrun fun enia ti o tọ li
oju rẹ̀ li ọgbọ́n, ati ìmọ ati ayọ̀ : ṣugbọn
ẹlẹṣẹ li o fi ìṣẹ́ fun, lati ma kó jọ ati lati
ma tò jọ ki on ki o le ma fi fun ẹni rere
niwaju Ọlọrun. Eyi pẹlu asan ni ati imu-
lẹmofo.

## ORI 3.

OLUKULUKU ohun li akoko wà fun, ati
ìgba fun iṣẹ gbogbo labẹ ọrun.
2 Ìgba bibini, ati ìgba kikú, ìgba gbi-
gbin ati ìgba kika ohun ti a gbin ;

Digitized by Google

3 Ìgba pipa ati ìgba imularada; ìgba wiwo lulẹ ati ìgba kikọ;

4 Ìgba sisọkun ati ìgba rirẹrín; ìgba ṣiṣọ̀fọ ati igba jijo;

5 Ìgba kikó okuta danu, ati ìgba kiko okuta jọ; ìgba fifọwọkoni mọra, ati ìgba fifasẹhin ni fifọwọkoni mọra;

6 Ìgba wiwari, ati ìgba sisọni; ìgba pipamọ́ ati ìgba ṣiṣatì;

7 Ìgba fifaya, ati ìgba rirán; ìgba didakẹ, ati ìgba fifọhùn:

8 Ìgba fifẹ, ati ìgba kikorira; ìgba ogun, ati ìgba alafia.

9 Ere kili ẹniti nṣiṣẹ ni ninu eyiti o nṣe lãla?

10 Mo ti ri ìṣẹ́ ti Ọlọrun fi fun awọn ọmọ enia lati ma ṣíṣẹ ninu rẹ̀.

11 O ti ṣe ohun gbogbo daradara ni ìgba tirẹ̀; pẹlupẹlu o fi aiyeraiye si wọn li aiya, bẹ̃li ẹnikan kò le ridi iṣẹ na ti Ọlọrun nṣe lati ipilẹṣẹ titi de opin.

12 Emi mọ̀ pe kò si rere ninu wọn, bikoṣe ki enia ki o ma yọ̀, ki o si ma ṣe rere li aiya rẹ̀.

13 Ati pẹlu ki olukuluku enia ki o ma jẹ ki o si ma mu, ki o si ma jadùn gbogbo lãla rẹ̀, ẹ̀bun Ọlọrun ni.

14 Emi mọ̀ pe ohunkohun ti Ọlọrun ṣe yio wà lailai: a kò le fi ohun kan kún u, bẹ̃li a kò le mu ohun kan kuro ninu rẹ̀; Ọlọrun si ṣe eyi ki enia ki o le ma bẹ̀ru rẹ̀.

15 Ohun ti o ti wà ri mbẹ nisisiyi, ati eyi ti yio si wà, o ti wà na; Ọlọrun si bère eyi ti o ti kọja lọ.

16 Ati pẹlupẹlu mo ri ibi idajọ labẹ õrùn pe ìwa buburu mbẹ nibẹ; ati ni ibi ododo, pe aiṣedẽde mbẹ nibẹ.

17 Mo wi li aiya mi pe, Ọlọrun yio ṣe idajọ olododo ati enia buburu: nitoripe ìgba kan mbẹ fun ipinnu ati fun iṣẹ gbogbo.

18 Mo wi li aiya mi niti ìwa awọn ọmọ enia; ki Ọlọrun ki o le fi wọn hàn, ati ki nwọn ki o le ri pe ẹran ni awọn tikalawọn fun ara wọn.

19 Nitoripe ohun ti nṣe ọmọ enia nṣe ẹran; ani ohun kanna li o nṣe wọn: bi ekini ti nkú bẹ̃li ekeji nkú; nitõtọ ẹmi kanna ni gbogbo wọn ní, bẹ̃li enia kò li ọlá jù ẹran lọ: nitoripe asan ni gbogbo rẹ̀.

20 Nibikanna ni gbogbo wọn nlọ; lati inu erupẹ wa ni gbogbo wọn, gbogbo wọn si tun pada di erupẹ.

21 Tali o mọ̀ ẹmi ọmọ enia ti ngoke si apa òke, ati ẹmi ẹran ti nsọkalẹ si isalẹ ilẹ?

22 Nitorina mo woye pe kò si ohun ti o dara jù ki enia ki o ma yọ̀ ni iṣẹ ara rẹ̀; nitori eyini ni ipin rẹ̀: nitoripe tani yio mu u wá ri ohun ti yio wà lẹhin rẹ̀.

## ORI 4.

BẸ̃NI mo pada, mo si rò inilara gbogbo ti a nṣe labẹ õrùn; mo si wò omije awọn ti a nnilara, nwọn kò si ni olutunu; ati lọwọ aninilara wọn ni ipá wà; ṣugbọn nwọn kò ni olutunu.

2 Nitorina mo yìn okú ti o ti kú pẹ jù awọn alãye ti o wà lãye sibẹ.

3 Nitõtọ, ẹniti kò ti isi san jù awọn mejeji; ẹniti kò ti iri iṣẹ buburu ti a nṣe labẹ õrùn.

4 Ati pẹlu, mo rò gbogbo lãla ati ìmọ iṣẹ gbogbo, pe eyiyi ni ilara ẹnikini lati ọdọ ẹnikeji rẹ̀. Asan li eyi pẹlu ati imulẹmofo.

5 Aṣiwère fọwọ rẹ̀ lọwọ, o si njẹ ẹran-ara rẹ̀.

6 Onjẹ ikunwọ kan pẹlu idakẹjẹ, o san jù ikunwọ meji lọ ti o kun fun lãla ati imulẹmofo.

7 Nigbana ni mo pada, mo si ri asan labẹ õrun.

8 Ẹni kanṣoṣo wà, kò si ni ẹnikeji; nitõtọ kò li ọmọ, bẹ̃ni kò li arakọnrin: sibẹ kò si opin ninu lãla rẹ̀ gbogbo; bẹ̃li ọrọ̀ kò tẹ oju rẹ̀ lọrun: bẹ̃ni kò si wipe, Nitori tali emi nṣe lãla, ti mo si nfi ire dù ọkàn mi? Eyi pẹlu asan ni ati iṣẹ òṣi.

9 Ẹni meji san jù ẹnikan; nitori nwọn ni ère rere fun lãla wọn.

10 Nitoripe bi nwọn ba ṣubu, ẹnikini yio gbe ọ̀gba rẹ̀ dide: ṣugbọn egbe ni fun ẹniti o ṣe on nikan nigbati o ba ṣubu; ti kò li ẹlomiran ti yio gbé e dide.

11 Ati pẹlu, bi ẹni meji ba dubulẹ pọ̀, nigbana ni nwọn o mõru: ṣugbọn ẹnikan yio ha ti ṣe mõru?

12 Bi ẹnikan ba kọlu ẹnikan, ẹni meji yio kò o loju; ati okùn onikọ mẹta kì iyá fàja.

13 Otoṣi ọpẹ̀rẹ ti o ṣe ọlọgbọ́n, o san jù arugbo ati aṣiwère ọba lọ ti kò mọ̀ bi a ti igbà ìmọran.

14 Nitoripe lati inu tubu li o ti jade wá ijọba; bi a tilẹ ti bi i ni talaka ni ijọba rẹ̀.

15 Mo ri gbogbo alãye ti nrìn labẹ õrun, pẹlu ọpẹ̀rẹ ekeji ti yio dide duro ni ipò rẹ̀.

16 Kò si opin gbogbo awọn enia na, ani fun gbogbo awọn ti on wà ṣiwaju wọn: awọn pẹlu ti mbọ̀ lẹhin kì yio yọ̀ si i. Nitõtọ asan li eyi pẹlu ati imulẹmofo.

Digitized by Google

## ORI 5.

PA ẹsẹ rẹ mọ́ nigbati iwọ ba nlọ si ile Ọlọrun, ki iwọ ki o si mura ati gbọ́ jù ati ṣe irubọ aṣiwère: nitoriti nwọn kò rò pe nwọn nṣe ibi.

2 Máṣe fi ẹnu rẹ yara, ki o má si jẹ ki aiya rẹ ki o yara sọ ọ̀rọ niwaju Ọlọrun: nitoriti Ọlọrun mbẹ li ọrun, iwọ si mbẹ li aiye: nitorina jẹ ki ọ̀rọ rẹ ki o mọ̀ ni ìwọn.

3 Nitoripe nipa ọ̀pọlọpọ iṣẹ ni alá ti iwá; bẽni nipa ọ̀pọlọpọ ọ̀rọ li ãmọ̀ ohùn aṣiwère.

4 Nigbati iwọ ba jẹ ẹjẹ́ fun Ọlọrun, máṣe duro pẹ lati san a: nitori kò ni inudidun si aṣiwère: san eyi ti iwọ jẹ́jẹ.

5 O san ki iwọ ki o má jẹ ẹjẹ́, jù ki iwọ ki o jẹ ẹjẹ́, ki o má san a.

6 Máṣe jẹ ki ẹnu rẹ ki o mu ara rẹ ṣẹ̀: ki iwọ ki o má si ṣe wi niwaju iranṣẹ Ọlọrun pe, èṣi li o ṣe: nitori kili Ọlọrun yio ṣe binu si ohùn rẹ, a si ba iṣẹ ọwọ rẹ jẹ?

7 Nitoripe bi ninu ọ̀pọlọpọ alá ni asan wà, bẽni ninu ọ̀pọlọpọ ọ̀rọ pẹlu: ṣugbọn iwọ bẹ̀ru Ọlọrun.

8 Bi iwọ ba ri inilara awọn olupọnju, ati ifi agbara yi idajọ ati otitọ pada ni igberiko, máṣe jẹ ki ẹnu ki o yà ọ si ọ̀ran na: nitoripe ẹniti o ga jù nṣọ ẹniti o ga, ati ẹni-giga-julọ wà lori wọn.

9 Pẹlupẹlu ère ilẹ ni fun gbogbo enia: a si nsìn ọba tikalarẹ̀ pãpa lati inu oko wa.

10 Ẹniti o ba fẹ fadaka, fadaka kì yio tẹ́ ẹ lọrun; bẽli ẹniti o fẹ ọrọ̀ kì yio tẹ́ ẹ lọrun: asan li eyi pẹlu.

11 Nigbati ẹrù ba npọ̀ si i, awọn ti o si njẹ ẹ a ma pọ̀ si i: ore ki tilẹ ni fun ẹniti o ni i bikoṣepe ki nwọn ki o ma fi oju wọn wò o?

12 Didùn ni orun oniṣẹ, iba jẹ onjẹ diẹ tabi pupọ: ṣugbọn itẹlọrun ọlọrọ̀ kì ijẹ ki o sùn.

13 Ibi buburu kan mbẹ ti mo ri labẹ õrùn, eyini ni pe, ọrọ̀ ti a pamọ́ fun ifarapa awọn ti o ni i.

14 Nitori ọrọ̀ wọnni a ṣegbe nipa iṣẹ buburu; bi o si bi ọmọkọnrin kan, kò ni nkan lọwọ rẹ̀.

15 Bi o ti ti inu iya rẹ̀ jade wá, ihoho ni yio si tun pada lọ bi o ti wá, kì yio si mu nkan ninu lãla rẹ̀, ti iba mu lọ lọwọ rẹ̀.

16 Ibi buburu li eyi pẹlu, pe li ọ̀na gbogbo, bi o ti wá, bẽni yio si lọ: ère ki si ni fun ẹniti nṣe lãla fun afẹfẹ?

17 Li ọjọ rẹ̀ gbogbo pẹlu, o njẹun li ọ̀kunkun, o si ni ibinujẹ pupọ ati àrun ati irora rẹ̀.

18 Kiyesi eyi ti mo ri: o dara o si yẹ fun enia, ki o jẹ, ki o si mu, ki o si ma jẹ alafia ninu gbogbo lãla rẹ̀ ti o ṣe labẹ õrùn, ni iye ọjọ aiye rẹ̀ gbogbo, ti Ọlọrun fi fun u: nitori eyi ni ipin tirẹ̀.

19 Bi Ọlọrun ba fi ọrọ̀ fun ẹnikẹni, ti o si fun u li agbara ati jẹ ninu rẹ̀: ati lati mu ipin rẹ̀, ati lati yọ̀ ninu lãla rẹ̀; eyi pẹlu ẹ̀bun Ọlọrun ni.

20 Nitoriti kì yio ranti ọjọ aiye rẹ̀ pọju; nitoriti Ọlọrun da a lohùn ninu ayọ̀ ọkàn rẹ̀.

## ORI 6.

IBI kan mbẹ ti mo ri labẹ õrùn, o si ṣọpọ lãrin awọn ọmọ enia.

2 Ẹniti Ọlọrun fi ọrọ̀, ọlà ati ọlá fun, ti kò si si nkan ti o si kù fun ọkàn rẹ̀ ninu ohun gbogbo ti o fẹ, ṣugbọn ti Ọlọrun kò fun u li agbara ati jẹ ninu rẹ̀, ṣugbọn awọn ajeji enia li o njẹ ẹ: asan li eyi, àrun buburu si ni.

3 Bi ọkọnrin kan bi ọgọrun ọmọ, ti o si wà li ọdun pupọ, tobẽ ti ọjọ ọdun rẹ̀ pọ̀, ti ọkàn rẹ̀ kò si kun fun ohun didara, ati pẹlu ti a kò si sinkú rẹ̀; mo ni, ọmọ iṣẹnu san jù u lọ.

4 Nitoripe lasan li o wá, o si lọ li ọ̀kunkun, ọ̀kunkun li a o si fi bo orukọ rẹ̀ mọlẹ.

5 Pẹlupẹlu on kò ri õrùn kò mọ ohun kan: eyi ni isimi jù ekeji lọ.

6 Ani bi o tilẹ wà ni ẹgbẹrun ọdun lẹrinmeji, ṣugbọn kò ri rere: ibikanna ki gbogbo wọn ha nrè?

7 Gbogbo lãla enia ni fun ẹnu rẹ̀, ṣugbọn a kò ti itẹ adùn ọkàn rẹ̀ lọrun.

8 Nitoripe ère kili ọlọgbọ́n ni jù aṣiwère lọ? kini talaka ni ti o mọ̀ bi a ti rin niwaju awọn alãye?

9 Eyiti oju ri san jù irokakiri ifẹ lọ; asan li eyi pẹlu ati imulẹmofo.

10 Eyi ti o wà, a ti da orukọ rẹ̀ ri, a si ti mọ̀ ọ pe, enia ni: bẽni kò le ba ẹniti o lagbara jù u lọ jà.

11 Kiyesi i ohun pupọ li o wà ti nmu asan bi si i, ère kili enia ni?

12 Nitoripe tali o mọ̀ ohun ti o dara fun enia li aiye yi, ni iye ọjọ asan rẹ̀ ti nlọ bi ojiji? nitoripe tali o le sọ fun enia li ohun ti yio wà lẹhin rẹ̀ labẹ õrun?

## ORI 7.

ORUKỌ rere dara jù ororo ikunra; ati ọjọ ikú jù ọjọ ibi enia lo

Digitized by Google

2 O dara lati lọ si ile ọ̀fọ jù ati lọ si ile àse: nitoripe eyi li opin gbogbo enia; alãye yio si pa a mọ́ li aiya rẹ̀.
3 Ibinujẹ san jù ẹrín: nitoripe nipa ifaro oju a si mu aiya san.
4 Aiya ọlọgbọ́n mbẹ ni ile ọ̀fọ; ṣugbọn aiya aṣiwère ni ile iré.
5 O san lati gbọ́ ibawi ọlọgbọ́n jù ki enia ki o fetisi orin aṣiwère.
6 Nitoripe bi itapàpa ẹgún labẹ ìkoko, bẽli ẹrín aṣiwère: asan li eyi pẹlu.
7 Nitõtọ inilara mu ọlọgbọ́n enia sinwin; ọrẹ a si ba aiya jẹ.
8 Opin nkan san jù ipilẹṣẹ rẹ̀ lọ: ati onisuru ọkàn jù ọlọkàn igberaga.
9 Máṣe yara li ọkàn rẹ lati binu, nitoripe ibinu simi li aiya aṣiwère.
10 Iwọ máṣe wipe, nitori kili ọjọ iṣaju ṣe san jù wọnyi lọ? nitoripe iwọ kò fi ọgbọ́n bere niti eyi.
11 Ọgbọ́n dara gẹgẹ bi iní, ati nipasẹ rẹ̀ ère wà fun awọn ti nri õrùn.
12 Nitoripe ãbò li ọgbọ́n, ani bi owo ti jẹ́ abò: ṣugbọn ère ìmọ ni pe, ọgbọ́n fi ìye fun awọn ti o ni i.
13 Wò iṣẹ Ọlọrun: nitoripe, tali o le mu eyini tọ́ ti on ṣe ni wiwọ?
14 Li ọjọ alafia, mã yọ̀, ṣugbọn li ọjọ ipọnju, ronu pe, bi Ọlọrun ti da ekini bẽli o da ekeji, niti di eyi pe ki enia ki o máṣe ri nkan ti mbọ̀ lẹhin rẹ̀.
15 Ohun gbogbo ni mo ri li ọjọ asan mi: olõtọ enia wà ti o ṣegbé ninu ododo rẹ̀, ati enia buburu wà ti ọjọ rẹ̀ pẹ ninu ìwa buburu rẹ̀.
16 Iwọ máṣe ododo aṣeleke; bẽni ki iwọ ki o máṣe fi ara rẹ ṣe ọlọgbọ́n aṣeleke: nitori kini iwọ o ṣe run ara rẹ?
17 Iwọ máṣe buburu aṣeleke, bẽni ki iwọ ki o má ṣiwère; nitori kini iwọ o ṣe kú ki ọjọ rẹ ki o to pe?
18 O dara ki iwọ ki o dì eyi mu; pẹlupẹlu iwọ máṣe yọ ọwọ rẹ kuro ninu eyi: nitori ẹniti o bẹru Ọlọrun ni yio yọ kuro ninu rẹ̀ gbogbo.
19 Ọgbọ́n mu ọlọgbọ́n lara le jù enia alagbara mẹwa lọ ti o wà ni ilu.
20 Nitoriti kò si olõtọ enia lori ilẹ, ti nṣe rere ti kò si dẹṣẹ.
21 Pẹlupẹlu máṣe fiyesi gbogbo ọ̀rọ ti a nsọ; ki iwọ ki o má ba gbọ́ ki iranṣẹ rẹ ki o bu ọ.
22 Nitoripe nigba pupọ pẹlu li aiya rẹ mọ̀ pe iwọ tikalarẹ pẹlu ti bu awọn ẹlomiran.
23 Idi gbogbo wọnyi ni mo fi ọgbọ́n wá; mo ni, emi o gbọ́n: ṣugbọn ọ̀na rẹ̀ jin si mi.
24 Eyi ti o jinna, ti o si jinlẹ gidigidi, tali o le wá a ri?
25 Mo fi aiya mi si i lati mọ̀, on ati wadi, on ati ṣe afẹri ọgbọ́n ati oye, on ati mọ̀ ìwa buburu wère, ani ti wère ati ti isinwin:
26 Mo si ri ohun ti o korò jù ikú lọ, ani obirin ti aiya rẹ̀ iṣe idẹkun ati àwọn, ati ọwọ rẹ̀ bi ọbára: ẹnikẹni ti inu Ọlọrun dùn si yio bọ lọwọ rẹ̀; ṣugbọn ẹlẹṣẹ li a o ti ọwọ rẹ̀ mu.
27 Kiyesi i, eyi ni mo ri, bẽli oniwasu wi, ni wiwadi rẹ̀ li ọkọkan lati ri oye.
28 Ti ọkàn mi nwakiri sibẹ, ṣugbọn emi kò ri: ọkọnrin kanṣoṣo ninu ẹgbẹrun ni mo ri; ṣugbọn obirin kan ninu gbogbo awọn wọnni, emi kò ri.
29 Kiyesi i, eyi nikanṣoṣo ni mo ri, pe, Ọlọrun ti da enia ni iduroṣinṣin; ṣugbọn nwọn ti ṣe afẹri ihumọkihumọ.

## ORI 8.

TALI o dabi ọlọgbọ́n enia? tali o si mọ̀ itumọ nkan? Ọgbọ́n enia mu oju rẹ̀ dán, ati igboju rẹ̀ li a o si yipada.
2 Mo ba ọ mọ̀ ọ pe, ki iwọ ki o pa ofin ọba mọ́, eyini si ni nitori ibura Ọlọrun.
3 Máṣe yara ati jade kuro niwaju rẹ̀: máṣe duro ninu ohun buburu; nitori ohun ti o wù u ni iṣe.
4 Nibiti ọ̀rọ ọba gbe wà, agbara mbẹ nibẹ; tali o si le wi fun u pe, kini iwọ nṣe ni?
5 Ẹnikẹni ti o pa ofin mọ́ kì yio mọ̀ ohun buburu: aiya ọlọgbọ́n enia si mọ̀ ìgba ati àṣa.
6 Nitoripe ohun gbogbo ti o wuni ni ìgba ati àṣa wà fun, nitorina òṣi enia pọ̀ si ori ara rẹ̀.
7 Nitoriti kò mọ̀ ohun ti mbọ̀: tali o si le wi fun u bi yio ti ri.
8 Kò si enia kan ti o lagbara lori ẹmi lati da ẹmi duro; bẽni kò si lagbara li ọjọ ikú: kò si iránpada ninu ogun na; bẽni ìwa buburu kò le gbà awọn oluwa rẹ̀.
9 Gbogbo nkan wọnyi ni mo ri, mo si fiyè si iṣẹ gbogbo ti a nṣe labẹ õrùn: ìgba kan mbẹ ninu eyi ti ẹnikan nṣe olori ẹnikeji fun ifarapa rẹ̀.
10 Bẽni mo si ri isinkú enia buburu, ati awọn ti o ṣe otitọ ti o wá ti o si lọ kuro ni ibi mimọ́, a si gbagbe wọn ni ilu na: asan li eyi pẹlu.
11 Nitoriti a kò mu idajọ ṣẹ kánkán si

iṣẹ buburu, nitorina aiya awọn ọmọ enia
mura pāpa lati huwa ibi.
12 Bi ẹlẹṣẹ tilẹ ṣe ibi nigba ọgọrun, ti
ọjọ rẹ̀ si gùn, ṣugbọn nitõtọ, emi mọ̀ pe
yio dara fun awọn ti o bẹ̀ru Ọlọrun, ti o
bẹ̀ru niwaju rẹ̀ :
13 Ṣugbọn kì yio dara fun enia buburu,
bẹ̃ni kì yio fa ọjọ rẹ̀ gun ti o dabi ojiji,
nitoriti kò bẹ̀ru niwaju Ọlọrun.
14 Asan kan mbẹ ti a nṣe li aiye ; niti
pe, olõtọ enia wà, awọn ti o nri fun bi iṣẹ
buburu ; ati pẹlu, enia buburu wà, awọn
ti o nri fun bi iṣẹ olododo : mo ni asan li
eyi pẹlu.
15 Nigbana ni mo yìn iré, nitori enia
kò ni ohun rere labẹ õrùn jù jijẹ ati mimu,
ati ṣiṣe ariya : nitori eyini ni yio ba a duro
ninu lãla rẹ̀ li ọjọ aiye rẹ̀, ti Ọlọrun fi fun
u labẹ õrùn.
16 Nigbati mo fi aiya mi si ati mọ̀ ọgbọ́n,
on ati ri ohun ti a ṣe lori ilẹ : (ẹnikan sa
wà pẹlu ti kò fi oju rẹ̀ ba orun li ọsan ati
li oru.)
17 Nigbana ni mo wò gbogbo iṣẹ Ọlọrun,
pe enia kò le ridi iṣẹ ti a nṣe labẹ õrùn :
nitoripe bi enia tilẹ gbiyanju ati wadi rẹ̀,
sibẹ kì yio le ri i ; ati pẹlupẹlu bi ọlọgbọ́n
enia rò lati wadi rẹ̀, sibẹ kì yio le ridi rẹ̀.

## ORI 9.

NITORI nkan yi ni mo rò li aiya mi, ani
lati wadi gbogbo eyi pe, olododo, ati
ọlọgbọ́n, ati iṣẹ wọn, lọwọ Ọlọrun li o wà :
ifẹni ati irira, kò si ẹniti o mọ̀, gbogbo eyi
wà niwaju wọn.
2 Bakanna li ohun gbogbo ri fun gbogbo
wọn : ohun kanna li o nṣe si olododo, ati
si ẹni buburu ; si enia rere, ati si mimọ́ ati
si alaimọ́ ; si ẹniti nrubọ, ati si ẹniti kò
rubọ : bi enia rere ti ri, bẹ̃ li ẹlẹṣẹ ; ati
ẹniti mbura bi ẹniti o bẹ̀ru ibura.
3 Eyi ni ibi ninu ohun gbogbo ti a nṣe
labẹ õrùn, pe iṣẹ kanna ni si gbogbo wọn :
ati pẹlu, aiya awọn ọmọ enia kún fun ibi,
isinwin mbẹ ninu wọn nigbati wọn wà
lãye, ati lẹhin eyini ; nwọn a lọ sọdọ awọn
okú.
4 Nitoripe tali ẹniti a yàn, ti ireti alãye
wà fun : nitoripe ààye ajá san jù okú kiniun
lọ.
5 Nitori alãye mọ̀ pe awọn o kú ; ṣugbọn
awọn okú kò mọ̀ ohun kan, bẹ̃ni nwọn kì
ili ère mọ ; nitori iranti wọn ti di igbagbe.
6 Ifẹ wọn pẹlu, ati irira wọn, ati ilara
wọn, o parun nisisiyi ; bẹ̃ni nwọn kò si ni
ipin mọ lailai ninu ohun gbogbo ti a nṣe
labẹ õrùn.
7 Ma ba tirẹ lọ, ma fi ayọ̀ jẹ onjẹ rẹ, ki
o si mã fi inu-didun mu ọti-waini rẹ : nito-
ripe Ọlọrun tẹwọgba iṣẹ rẹ nisisiyi.
8 Jẹ ki aṣọ rẹ ki o ma fún nigbagbogbo ;
ki o má si jẹ ki ori rẹ ki o ṣe alaini ororo
ikunra,
9 Ma fi ayọ̀ ba aya rẹ gbe ti iwọ fẹ ni
gbogbo ọjọ aiye asan rẹ, ti o fi fun ọ labẹ
õrùn ni gbogbo ọjọ asan rẹ : nitori eyini ni
ipin tirẹ li aiye yi, ati ninu lãla ti iwọ ṣe
labẹ õrùn.
10 Ohunkohun ti ọwọ rẹ ri ni ṣiṣe, fi
agbara rẹ ṣe e ; nitoriti kò si ete, bẹ̃ni kò
si ìmọ, tabi ọgbọ́n, ni isa-okú nibiti iwọ
nrè.
11 Mo pada, mo si ri labẹ õrùn, pe ire-
ije kì iṣe ti ẹniti o yara, bẹ̃li ogun kì iṣe ti
alagbara, bẹ̃li onjẹ kì iṣe ti ọlọgbọ́n, bẹ̃li
ọrọ̀ kì iṣe ti ẹni oye, bẹ̃li ojurere kì iṣe ti
ọlọgbọ́n-inu ; ṣugbọn ìgba ati eṣe nṣe si
gbogbo wọn.
12 Nitoripe enia pẹlu kò mọ̀ ìgba tirẹ̀ ;
bi ẹja ti a mu ninu àwọn buburu, ati bi
ẹiyẹ ti a mu ninu okùn ; bẹ̃li a ndẹ awọn
ọmọ enia ni ìgba buburu, nigbati o ṣubu lù
wọn lojiji.
13 Ọgbọ́n yi ni mo ri pẹlu labẹ õrùn, o
si dabi ẹnipe o tobi fun mi.
14 Ilu kekere kan wà, ati enia diẹ ninu
rẹ̀ ; ọba nla kan si ṣigun tọ̀ ọ lọ, o si dótì
i, o si mọ ile-iṣọ ti o tobi tì i.
15 A si ri ọkọnrin talaka ọlọgbọ́n ninu
rẹ̀, on si fi ọgbọ́n rẹ̀ gbà ilu na silẹ ; ṣu-
gbọn kò si ẹnikan ti o ranti ọkọnrin talaka
na.
16 Nigbana ni mo wipe, Ọgbọ́n san jù
agbara lọ ; ṣugbọn a kẹgan ọgbọ́n ọkọnrin
talaka na, ohùn rẹ̀ kò si to òke.
17 A ngbọ́ ọ̀rọ ọlọgbọ́n enia ni pẹlẹ jù
igbe ẹniti njẹ olori ninu awọn aṣiwère.
18 Ọgbọ́n san jù ohun-elo ogun : ṣugbọn
ẹlẹṣẹ kan o ba ohun didara pupọ jẹ.

## ORI 10.

OKÚ eṣinṣin o mu ororo-ikunra alapolu
bajẹ ki o ma run õrùn buburu : bẹ̃ni
wère diẹ wuwo jù ọgbọ́n ati ọlá lọ.
2 Aiya ọlọgbọ́n mbẹ li ọwọ ọtún rẹ̀ ; ṣu-
gbọn aiya aṣiwère li ọwọ òsi rẹ̀.
3 Ati pẹlu nigbati ẹniti o ṣiwère ba nrìn
li ọ̀na, ọgbọ́n rẹ̀ a fò lọ, on a si wi fun
olukuluku enia pe aṣiwère li on.
4 Bi ọkàn ijoye ba ru si ọ, máṣe fi ipò rẹ
silẹ ; nitoripe itumba ama tù ẹ̀ṣẹ nla.

Digitized by Google

5 Buburu kan mbẹ ti mo ri labẹ õrùn,
bi ìṣina ti o ti ọdọ awọn ijoye wá.
6 A gbe aṣiwère sipò ọlá, awọn ọlọrọ̀ si
joko nipò ẹhin.
7 Mo ri awọn ọmọ-ọdọ lori ẹṣin, ati awọn
ọmọ-alade nrìn bi ọmọ-ọdọ ni ilẹ.
8 Ẹniti o wà iho ni yio bọ́ sinu rẹ̀;
ati ẹniti o si njá ọgbà tútù, ejo yio si bù u
ṣán.
9 Ẹnikan ti o nyi okuta ni yio si ti ipa
rẹ̀ ni ipalara; ati ẹniti o si nla igi ni yio si
wu li ewu.
10 Bi irin ba kújú, ti on kò si pọn oju
rẹ̀, njẹ ki on ki o fi agbara si i; ṣugbọn ère
ọgbọ́n ni lati fi ọ̀na hàn.
11 Nitõtọ bi ejo ba bu ni ṣán lainitùju;
njẹ ère kì yio si fun onitùju.
12 Ọ̀rọ ẹnu ọlọgbọ̀n li ore-ọfẹ; ṣugbọn
ète aṣiwère ni yio gbe ara rẹ̀ mì.
13 Ipilẹṣẹ ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ ni wère: ati opin
ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ ni isinwin iparun.
14 Aṣiwère pẹlu kún fun ọ̀rọ pupọ: enia
kò le sọ ohun ti yio ṣẹ; ati ohun ti yio wà
lẹhin rẹ̀, tali o le wi fun u?
15 Lãla aṣiwère da olukuluku wọn li
agara, nitoriti kò mọ̀ bi a ti lọ si ilu.
16 Egbé ni fun ọ, iwọ ilẹ, nigbati ọba
rẹ ba ṣe ọmọde, ti awọn ọmọ-alade rẹ
njẹun ni kutukutu.
17 Ibukún ni fun ọ, iwọ ilẹ, nigbati ọba
rẹ ba jẹ ọmọ ọlọlá, ti awọn ọmọ-alade rẹ
njẹun li akoko ti o yẹ, fun ilera ti kì si iṣe
fun ọti amupara!
18 Nipa ilọra pupọ igi ile a hù; ati nipa
ọlẹ ọwọ, ile a si ma jò.
19 Ẹrín li a nsàse fun, ati ọti-waini ni
imu inu alãye dùn: owo si ni idahùn ohun
gbogbo.
20 Máṣe bu ọba, ki o má ṣe ninu èro rẹ;
máṣe bu ọlọrọ̀ ni iyẹwu rẹ; nitoripe ẹiyẹ
oju-ọrun yio gbe ohùn na lọ, ohun ti o ni
iyẹ-apá yio si sọ ọ̀ran na.

## ORI 11.

FUN onjẹ rẹ si oju omi; nitoriti iwọ o ri
i lẹhin ọjọ pupọ.
2 Fi ipin fun meje ati fun mẹjọ pẹlu,
nitoriti iwọ kò mọ̀ ibi ti yio wà laiye.
3 Bi awọsanma ba kún fun òjo, nwọn a
si tu dà si aiye: bi igi ba si wó siha gusu
tabi siha ariwa, nibiti igi na gbe ṣubu si,
nibẹ ni yio si ma gbe.
4 Ẹniti o nkiyesi afẹfẹ kì yio funrugbin;
ati ẹniti o si nwòju awọsanma kì yio ṣe
ikore.
5 Bi iwọ kò ti mọ ipa-ọ̀na afẹfẹ, tabi bi
egungun ti idàgba ninu aboyun: ani bẹ̃ni
iwọ kò le mọ̀ iṣẹ Ọlọrun ti nṣe ohun gbo-
gbo.
6 Ni kutukutu fún irugbin rẹ, ati li
aṣãlẹ máṣe da ọwọ rẹ duro: nitori ti iwọ
kò mọ̀ eyi ti yio ṣe rere, yala eyi tabi eyi-
ni, tabi bi awọn mejeji yio dara bakanna.
7 Nitõtọ imọlẹ dùn ati ohun didara ni
fun oju lati wò õrùn.
8 Ṣugbọn bi enia wà li ọ̀pọlọpọ ọdun, ti
o si nyọ̀ ninu gbogbo wọn, sibẹ, jẹ ki o
ranti ọjọ òkunkun pe nwọn o pọ̀. Ohun
gbogbo ti mbọ̀, asan ni.
9 Mã yọ̀, iwọ ọdọmọde ninu ewe rẹ; ki
o si jẹ ki ọkàn rẹ ki o mu ọ laraya li ọjọ
ewe rẹ, ki o si ma rìn nipa ọ̀na ọkàn rẹ ati
nipa irí oju rẹ; ṣugbọn iwọ mọ̀ eyi pe,
nitori nkan wọnyi Ọlọrun yio mu ọ wá si
idajọ.
10 Nitorina ṣi ibinujẹ kuro li aiya rẹ, ki
o si mu ibi kuro li ara rẹ: nitoripe asan ni
igba-ewe ati ọmọde.

## ORI 12.

RANTI ẹlẹda rẹ nisisiyi li ọjọ ewe rẹ,
nigbati ọjọ ibi kò ti ide, ati ti ọdun
kò ti isunmọ etile, nigbati iwọ o wipe, emi
kò ni inudidùn ninu wọn;
2 Nigbati õrùn, tabi imọlẹ, tabi oṣupa
tabi awọn irawọ kò ti iṣu òkunkun, ati ti
awọsanma kò ti itun pada lẹhin òjo:
3 Li ọjọ ti awọn oluṣọ ile yio warìri, ati
ti awọn ọkọnrin alagbara yio tẹri wọn ba,
awọn õlọ̀ yio si dakẹ nitoriti nwọn kò to
nkan, ati awọn ti nwode loju ferese yio ṣu
òkunkun,
4 Ti ilẹkun yio si se ni igboro, nigbati
iró ọlọ yio rẹlẹ, ti yio si dide li ohùn kike
ẹiyẹ, ati ti gbogbo awọn ọmọbirin orin yio
rẹ̀ silẹ;
5 Ati pẹlu ti nwọn o bẹ̀ru ibi ti o ga, ti
iwarìri yio si wà li ọ̀na, ati ti igi almondi
yio tanna, ti ẹlẹnga yio di ẹrù, ti ifẹ yio si
ṣá: nitoriti ọkọnrin nlọ si ile rẹ̀ pipẹ, awọn
aṣọ̀fọ yio si ma yide kakiri.
6 Tabi ki okùn fadaka ki o to tu, tabi
ki ọpọn wura ki o to fọ, tabi ki ìṣa ki o to
fọ nibi isun, tabi ki ayikakẹkẹ ki o to kán
nibi kanga.
7 Nigbana ni erupẹ yio pada si ilẹ bi o
ti wà ri, ẹmi yio si pada tọ̀ Ọlọrun ti o fi i
funni.
8 Asan ninu asan, oniwasu wipe, gbogbo
rẹ̀ asan ni.
9 Ati pẹlu, nitori Oniwasu na gbọ́n, o si
nkọ́ awọn enia ni ìmọ pẹlu; nitõtọ o ṣe

Digitized by Google

akiyesi daradara, o si wadi, o si fi owe pupọ
lelẹ li ẹsẹsẹ.
10 Oniwasu wadi ati ri ọ̀rọ didùn eyiti a
si kọ, ohun iduro-ṣinṣin ni, ani ọ̀rọ otitọ.
11 Ọ̀rọ ọlọgbọ́n dabi ẹgún, ati awọn
olori akojọ-ọ̀rọ bi iṣó ti a kàn, ti a nfi fun
ni lati ọwọ oluṣọ-agutan kan wá.
12 Ati siwaju, lati inu eyi, ọmọ mi, ki
o gbà ìmọran: ninu kikọ iwe pupọ, opin
kò si: ati iwe kikà pupọ li ãrẹ̀ ara.
13 Opin gbogbo ọ̀rọ na ti a gbọ́ ni pe:
Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori
eyi ni fun gbogbo enia.
14 Nitoripe Ọlọrun yio mu olukuluku
iṣẹ wa sinu idajọ, ati olukuluku ohun ìkọ-
kọ, ibã ṣe rere, ibã ṣe buburu.

# ORIN SOLOMONI.

## ORI 1.

ORIN awọn orin ti iṣe ti Solomoni.
2 Jẹ ki o fi ifẹnukonu ẹnu rẹ̀ kò mi
li ẹnu nitori ifẹ rẹ sàn jù ọti-waini lọ.
3 Nitoriti õrun ikunra rere rẹ, orukọ rẹ
dabi ikunra ti a tú jade, nitorina ni awọn
wundia ṣe fẹ ọ.
4 Fà mi, awa o sare tọ̀ ọ: ọba ti mu mi
wá sinu iyẹwù rẹ̀: awa o yọ̀, inu wa o si
dùn si ọ, awa o ranti ifẹ rẹ jù ọti-waini lọ:
nwọn fẹ ọ nitõtọ.
5 Emi dú, ṣugbọn mo li ẹwà, Ẹnyin
ọmọbirin Jerusalemu, bi awọn agọ Kedari,
bi awọn aṣọ-tita Solomoni.
6 Máṣe wò mi, nitori pe mo dú, nitori
pe õrùn ti bojuwò mi: awọn ọmọ iyá mi
binu si mi; nwọn fi mi ṣe oluṣọ ọgba-ajara;
ṣugbọn ọgba-ajara temi li emi kò tọju.
7 Wi fun mi, Iwọ ẹniti ọkàn mi fẹ, ni-
biti iwọ nṣọ agutan; nibiti iwọ nmu agbo-
ẹran rẹ simi li ọsan; ki emi ki o má ba
dabi alãrẹ̀ ti o ṣina kiri pẹlu agbo-ẹran
awọn ẹgbẹ́ rẹ.
8 Bi iwọ kò ba mọ̀, Iwọ arẹwà julọ ninu
awọn obirin, jade lọ ni ipasẹ agbo-ẹran, ki
iwọ ki o si bọ́ awọn ọmọ ewurẹ rẹ lẹba agọ
awọn aluṣọ-agutan.
9 Olufẹ mi, mo ti fi ọ we ẹṣin mi ninu
kẹkẹ́ Farao.
10 Ẹrẹkẹ́ rẹ li ẹwà ninu ọwọ́ ohun ọṣọ́,
ọrùn rẹ ninu ilẹkẹ.
11 Awa o ṣe ọwọ́ ohun ọṣọ́ wura fun ọ,
pẹlu ami fadaka.
12 Nigbati ọba wà ni ibujoko ijẹun rẹ̀,
ororo mi rán õrun rẹ̀ jade.
13 Idi ojia ni olufẹ ọ̀wọ́n mi si mi; on
o ma gbe ãrin ọmu mi.
14 Olufẹ mi ri si mi bi ìdi itanná igi ki-
pressi ni ọgba-ajara Engedi.
15 Wò o, iwọ li ẹwà, olufẹ mi; wò o,
iwọ li ẹwà: iwọ li oju àdaba.
16 Wò o, iwọ li ẹwà, olufẹ mi, nitõtọ, o
wuni: ibusun wa pẹlu ni itura.
17 Igi kedari ni iti-igi ile wa, igi firi si
ni ẹkẹ́ wa.

## ORI 2.

EMI ni itanná eweko Ṣaroni, ati itanná
lili awọn afonifoji.
2 Bi itanná lili lãrin ẹgún, bẹ̃li olufẹ mi
ri lãrin awọn ọmọbirin.
3 Bi igi eleso lãrin awọn igi igbẹ, bẹ̃li
olufẹ mi ri lãrin awọn ọmọkọnrin. Emi fi
ayọ̀ nla joko labẹ ojiji rẹ̀, eso rẹ̀ si dùn mọ
mi li ẹnu.
4 O mu mi wá si ile ọti-waini, Ifẹ si ni
ọpagun rẹ̀ lori mi.
5 Fi akara didùn da mi duro, fi eso igi
tù mi ni inu: nitori aisàn ifẹ nṣe mi.
6 Ọwọ osì rẹ̀ mbẹ labẹ ori mi, ọwọ ọtún
rẹ̀ si gbá mi mọra.
7 Mo fi awọn abo egbin, ati awọn abo
agbọnrin igbẹ fi nyin bú, ẹnyin ọmọbirin
Jerusalemu, ki ẹ máṣe rú olufẹ mi soke, ki
ẹ má si ṣe ji i, titi yio fi wù u.
8 Ohùn olufẹ mi! sa wò o, o mbọ̀, o nfò
lori awọn òke, o mbẹ lori awọn òke kékeké.
9 Olufẹ mi dabi abo egbin, tabi ọmọ
agbọnrin: sa wò o, o duro lẹhin ogiri wa,
o yọju loju ferese, o nfi ara rẹ̀ hàn loju
ferese ọlọnà.
10 Olufẹ mi sọ̀rọ, o si wi fun mi pe,
Dide, olufẹ mi, arẹwà mi kanna, ki o si
jade kalọ.

Digitized by Google

11 Sa wò o, ìgba otutu ti kọja, òjo ti da,
o si ti lọ.
12 Awọn itanna eweko farahàn lori ilẹ;
akoko ikọrin awọn ẹiyẹ de, a si gbọ ohùn
àdaba ni ilẹ wa.
13 Igi ọ̀pọtọ so eso titun, awọn àjara
funni ni õrun daradara nipa itanná wọn.
Dide, olufẹ mi, arẹwà mi kanna, ki o si
jade kalọ.
14 Adaba mi, ti o wà ninu pàlapala
okuta, ni ibi ìkọkọ okuta, jẹ ki emi ri oju
rẹ, jẹ ki emi gbọ́ ohùn rẹ; nitori didùn ni
ohùn rẹ, oju rẹ si li ẹwà.
15 Mu awọn kọ̀lọkọlọ fun wa, awọn
kọ̀lọkọlọ kékeké ti mba àjara jẹ: nitori
àjara wa ni itanná.
16 Olufẹ mi ni temi, emi si ni tirẹ̀: o
njẹ lãrin awọn lili.
17 Titi ìgba itura ọjọ, titi ojiji yio fi sa-
lọ, yipada, olufẹ mi, ki iwọ ki o si dabi
abo egbin, tabi ọmọ agbọnrin lori awọn
oke Beteri.

## ORI 3.

LI oru lori akete mi, mo wá ẹniti ọkàn
mi fẹ: emi wá a, ṣugbọn emi kò ri i.
2 Emi o dide nisisiyi, emi o si rìn lọ ni
ilu, ni igboro, ati li ọ̀na gbòro ni emi o wá
ẹniti ọkàn mi fẹ: emi wá a, ṣugbọn emi kò
ri i.
3 Awọn oluṣọ ti nrìn ilu yika ri mi:
mo bère pe, Ẹ ha ri ẹniti ọkàn mi fẹ bi?
4 Ṣugbọn bi mo ti fi wọn silẹ gẹrẹ ni mo
ri ẹniti ọkàn mi fẹ: mo dì i mu, emi kò si
jọ̃rẹ̀ lọwọ, titi mo fi mu u wá sinu ile iya
mi, ati sinu iyẹwu ẹniti o loyun mi.
5 Mo fi awọn abo egbin ati awọn abo
agbọnrin igbẹ fi nyin bú, ẹnyin ọmọbirin
Jerusalemu, ki ẹ máṣe rú olufẹ mi soke, ki
ẹ má si ji i, titi yio fi wù u.
6 Tani eyi ti nti ijù jade wá bi ọwọ̀n
ẽfin, ti a ti fi ojia ati turari kùn lara, pẹlu
gbogbo etu olõrun oniṣowo?
7 Wo akete rẹ̀, ti iṣe ti Solomoni; ọgọta
akọni enia li o yi i ka ninu awọn akọni
Israeli.
8 Gbogbo wọn li o di idà mu, nwọn
gbọ́n ọgbọ́n ogun: olukuluku kọ́ idà rẹ̀
nitori ẹ̀ru li oru.
9 Solomoni, ọba, ṣe akete nla fun ara rẹ̀
lati inu igi Lebanoni.
10 O fi fadaka ṣe ọwọ̀n rẹ̀, o fi wura
ṣe ibi ẹhin rẹ̀, o fi elese aluko ṣe ibujoko rẹ̀,
inu rẹ̀ li o fi ifẹ tẹ́ nitori awọn ọmọbirin
Jerusalemu.
11 Ẹ jade lọ, Ẹnyin ọmọbirin Sioni, ki ẹ
si wò Solomoni ọba, ti on ti ade ti iya rẹ̀
fi de e li ọjọ igbeyawo rẹ̀, ati li ọjọ ayọ̀
ọkàn rẹ̀.

## ORI 4.

WÒ o, iwọ li ẹwà, olufẹ mi: wò o, iwọ li
ẹwà; iwọ li oju àdaba labẹ iboju rẹ:
irun rẹ dabi ọwọ́ ewurẹ, ti o dubulẹ lori
òke Gileadi.
2 Ehin rẹ dabi ọwọ́ ewurẹ ti a rẹ̀ ni irun,
ti o gòke lati ibi iwẹ̀ wá, olukuluku wọn bi
èjirẹ, kò si si ọkan ti o yàgan ninu wọn.
3 Ete rẹ dabi owu òdodo, ohùn rẹ si
dùn: ẹ̀rẹkẹ rẹ si dabi ẹlà pomegranate kan
labẹ iboju rẹ.
4 Ọrùn rẹ dabi ile-iṣọ Dafidi ti a kọ́ fun
ihamọra, lori eyi ti a fi ẹgbẹrun apata kọ́,
gbogbo wọn jẹ asà awọn alagbara.
5 Ọmu rẹ mejeji dabi abo egbin kekere
meji ti iṣe èjirẹ, ti njẹ lãrin itanna lili.
6 Titi ọjọ yio fi rọ̀, ti ojiji yio si fi fò lọ,
emi o lọ si òke nla ojia, ati si òke kékeké
turari.
7 Iwọ li ẹwà gbogbo, olufẹ mi; kò si
abawọ́n lara rẹ!
8 Ki a lọ kuro ni Lebanoni, iyawo mi,
ki a lọ kuro ni Lebanoni: wò lati ori òke
Amana, lati ori òke Ṣeniri ati Hermoni,
lati ibi ihò kiniun, lati òke awọn ẹkùn.
9 Iwọ ti gbà mi li ọkàn, arabirin mi,
iyawo! iwọ ti fi ọkan ninu ìwo oju rẹ, ati
ọkan ninu ẹwọ̀n ọrùn rẹ gbà mi li ọkàn.
10 Ifẹ rẹ ti dara to, arabirin mi, iyawo!
ifẹ rẹ ti sàn jù ọti-waini to! õrùn ikunra
rẹ si jù turari gbogbo lọ.
11 Iyawo! ète rẹ nkán bi afara-oyin:
oyin ati wàra mbẹ labẹ ahọn rẹ; õrùn aṣọ
rẹ si dabi õrùn Lebanoni.
12 Ọgbà ti a sọ ni arabirin mi, iyawo!
isun ti a sé, orisun ti a fi edidi dí.
13 Ohun gbigbìn rẹ agbala pomegranate
ni, ti on ti eso ti o wunni; kipressi ati
nardi.
14 Nardi ati saffroni; kalamusi, kinna-
moni, pẹlu gbogbo igi turari; ojia ati aloe,
pẹlu gbogbo awọn olori olõrun didùn.
15 Orisun ninu ọgba kanga omi iyè, ti
nṣan lati Lebanoni wá.
16 Ji afẹfẹ ariwa; si wá, iwọ ti gusu;
fẹ́ sori ọgbà mi, ki õrùn inu rẹ̀ le fẹ́ jade.
Jẹ ki olufẹ mi wá sinu ọgbà rẹ̀, ki o si jẹ
eso didara rẹ̀.

## ORI 5.

MO de inu ọgbà mi, arabirin mi, iyawo!
mo ti kó ojia mi pẹlu õrùn didùn mi

Digitized by Google

jọ; mo ti jẹ afara mi pẹlu oyin mi; mo ti
mu ọti-waini mi pẹlu wàra mi: Ẹ jẹun,
ẹnyin ọré; mu, ani mu amuyo, ẹnyin
olufẹ.
2 Emi sùn, ṣugbọn ọkàn mi ji, ohùn
olufẹ mi ni nkànkun, wipe: Ṣilẹkun fun
mi, arabirin mi, olufẹ mi, adaba mi, alai-
labawọn mi: nitori ori mi kún fun ìri, ati
ìdi irun mi fun kikán oru.
3 Mo ti bọ́ tòro mi; emi o ti ṣe gbe e
wọ̀? mo ti wẹ̀ ẹsẹ̀ mi; emi o ti ṣe sọ wọn
di aimọ́?
4 Olufẹ mi nawọ rẹ̀ lati inu ihò ilẹkùn,
inu mi sì yọ si i.
5 Emi dide lati ṣilẹkun fun olufẹ mi,
ojia si nkán lọwọ mi, ati ojia olõrùn didùn
ni ika mi sori idimu iṣikà.
6 Mo ṣilẹkun fun olufẹ mi; ṣugbọn
olufẹ mi ti fà sẹhin, o si ti lọ: aiya pá mi
nigbati o sọ̀rọ, mo wá a, ṣugbọn emi kò ri
i, mo pè e, ṣugbọn on kò da mi lohùn.
7 Awọn oluṣọ ti nrìn ilu kiri ri mi,
nwọn lù mi, nwọn sì ṣa mi lọgbẹ, awọn
oluṣọ gbà iborùn mi lọwọ mi.
8 Mo fi nyin bu, ẹnyin ọmọbirin Jeru-
salemu, bi ẹnyin ba ri olufẹ mi, ki ẹ wi
fun u pe, aisan ifẹ nṣe mi.
9 Kini olufẹ rẹ jù olufẹ miran lọ, iwọ
arẹwà julọ ninu awọn obirin? kini olufẹ rẹ
jù olufẹ miran ti iwọ fi nfi wa bú bẽ?
10 Olufẹ mi funfun, o si pọn, on ni ọlá
jù ọ̀pọlọpọ lọ.
11 Ori rẹ̀ dabi wura ti o dara julọ, ìdi
irun rẹ̀ dabi imọ̀ ọpẹ, o si du bi ẹiyẹ iwò.
12 Oju rẹ̀ dabi àdaba li ẹba odò, ti a fi
wàra wẹ̀, ti o si ngbe inu alafia.
13 Ẹrẹ̀kẹ rẹ̀ dabi ebè turari, bi olõrùn
didùn, ète rẹ̀ bi itanna lili, o nkán ojia
olõrùn didùn.
14 Ọwọ rẹ̀ dabi oruka wura ti o tò ni be-
rili yika, ara rẹ̀ bi ehin-erin didán ti a fi
saffire bò.
15 Itan rẹ̀ bi ọwọ̀n marbili, ti a gbe ka
ihò ìtẹbọ wura daradara; ìwo rẹ̀ dabi Le-
banoni, titayọ rẹ̀ bi igi kedari.
16 Ẹnu rẹ̀ dùn rekọja: ani o wunni
patapata. Eyi li olufẹ mi, eyi si li ọrẹ mi,
ẹnyin ọmọbirin Jerusalemu.

## ORI 6.

NIBO ni olufẹ rẹ lọ, iwọ arẹwà julọ ninu
awọn obirin? nibo li olufẹ rẹ yà si?
ki a le ba ọ wá a.
2 Olufẹ mi sọkalẹ lọ sinu ọgba rẹ̀, si ebè
turari, lati ma jẹ̀ ninu ọgbà, ati lati ká
itanna lili.
3 Emi ni ti olufẹ mi, olufẹ mi si ni ti
emi: o njẹ̀ lãrin itanna lili.
4 Iwọ yanju, olufẹ mi, bi Tirsa, o li ẹwà
bi Jerusalemu, ṣugbọn o li ẹ̀ru bi ogun pẹlu
ọpagun.
5 Mu oju rẹ kuro lara mi nitori nwọn
bori mi: irun rẹ si dabi ọwọ́ ewurẹ ti o
dubulẹ ni Gileadi.
6 Ehin rẹ dabi ọwọ́ agutan ti ngòke lati
ibi iwẹ̀ wá, ti olukuluku wọn bi ejirẹ, kò
si si ọkan ti o yàgan ninu wọn.
7 Bi ẹ̀la eso-pomegranate kan ni ẹrẹkẹ
rẹ ri lãrin iboju rẹ.
8 Ọgọta ayaba ni mbẹ, ati ọgọrin àle,
ati awọn wundia lainiye.
9 Ọkan ni adaba mi, alailabawọn mi;
on nikanṣoṣo ni ti iya rẹ̀, on ni ãyo ẹniti o
bi i. Awọn ọmọbirin ri i, nwọn si sure fun
u; ani awọn ayaba ati awọn àle,'nwọn si
yìn i.
10 Tali ẹniti ntàn jàde bi owurọ, ti o li
ẹwà bi oṣupa, ti o mọ́ bi õrùn, ti o si li ẹ̀ru
bi ogun pẹlu ọpagun?
11 Emi sọkalẹ lọ sinu ọgba eso igi, lati
ri awọn ẹka igi tutu afonifoji, ati lati ri bi
ajara ba ruwe, ati bi igi granate ba rudi.
12 Ki emi to mọ̀, ọkàn mi gbe mi ka
ori kẹkẹ́ Amminadibu.

## ORI 7.

PADA, pada, Ṣulamite; pada, pada, ki
awa ki o le wò ọ. Ẽṣe ti ẹnyin fẹ wò
Ṣulamite bi ẹnipe orin ijó Mahanaimu.
2 Ẹsẹ rẹ ti li ẹwà to ninu bata, iwọ ọmọ-
alade! orike itan rẹ dabi ohun ọṣọ́, iṣẹ
ọwọ ọlọgbọ́n onişọna.
3 Iwọ rẹ dabi ago ti kò ṣe alaini ọti, ara
rẹ dabi okiti alikama ti a fi lili yika.
4 Ọmú rẹ mejeji dabi abo ọmọ agbọnrin
meji ti iṣe èjirẹ.
5 Ọrùn rẹ dabi ile iṣọ ehin-erin; oju rẹ
dabi adagun ni Heṣboni, lẹba ẹnubode Ba-
trabbimu: imú rẹ dabi ile-iṣọ Lebanoni ti
o kọju si ihà Damasku.
6 Ori rẹ dabi Karmeli lara rẹ, ati irun
ori rẹ bi purpili; a fi aidì irun rẹ di ọba
mu.
7 O ti li ẹwà to, o si ti dara to, iwọ olufẹ
mi ninu adùn ifẹ!
8 Iduro rẹ yi dabi igi ọ̀pẹ ati ọmú rẹ bi
ṣiri eso àjara.
9 Mo ni, emi o gùn ọ̀pẹ lọ, emi o di
ẹka rẹ̀ mu: pẹlupẹlu nisisiyi ọmú rẹ pẹlu
yio dabi ṣiri àjara, ati õrùn imú rẹ bi eso
appili;
10 Ati ẹnu rẹ bi ọti-waini ti o dara jù,

Digitized by Google

ti o sọkalẹ kẹlẹkẹlẹ fun olufẹ mi, ti o nmu
ki etè awọn ti o sùn ki o sọ̀rọ.
11 Ti olufẹ mi li emi iṣe, ifẹ rẹ̀ si mbẹ
si mi.
12 Wá, olufẹ mi, jẹ ki a lọ si pápa; jẹ ki
a wọ̀ si iletò wọnni.
13 Jẹ ki a dide lọ sinu ọgba-àjara ni
kutukutu; jẹ ki a wò bi àjara ruwe, bi
itanná àjara ba là, ati bi igi granate ba
rudi: nibẹ li emi o fi ifẹ mi fun ọ.
14 Awọn eso mandraki fun ni li õrùn, li
ẹnu-ọ̀na wa ni onirũru eso ti o wunni, ọtun
ati ogbologbo, ti mo ti fi pamọ́ fun ọ, iwọ
olufẹ mi.

## ORI 8.

IWỌ iba jẹ dabi arakọnrin fun mi, ti o
mu ọ̀mú iya mi! emi iba ri ọ lode emi
iba fi ẹnu kò ọ lẹnu; lõtọ, nwọn kì ba fi
mi ṣe ẹlẹya.
2 Emi iba fọnahàn ọ, emi iba mu ọ wá
sinu ile iya mi, iwọ iba kọ́ mi: emi iba
mu ọ mu ọti-waini õrùn didùn, ati oje eso
granate mi.
3 Ọwọ osì rẹ̀ iba wà labẹ ori mi, ọwọ
ọtún rẹ̀ iba si gbá mi mọra.
4 Mo fi nyin bu, ẹnyin ọmọbirin Jeru-
salemu, ki ẹ máṣe rú olufẹ mi soke, ki ẹ
má si ṣe ji i, titi yio fi wù u.
5 Tani eyi ti ngòke lati aginju wá, ti o
fi ara tì olufẹ rẹ̀? mo ji ọ dide labẹ igi
eleso: nibẹ ni iya rẹ gbe bi ọ si, nibẹ li
ẹniti o bi ọ gbe bi ọ si.
6 Gbe mi ka aiya rẹ bi edidi, bi edidi le
apá rẹ: nitori ifẹ lagbara bi ikú; ijowu si
le bi isa-okú; jijo rẹ̀ dabi jijo iná, ani ọwọ
iná Oluwa.
7 Omi pupọ kò le paná ifẹ, bẽni kikún
omi kò le gbá a lọ, bi enia fẹ fi gbogbo ọrọ̀
rẹ̀ fun ifẹ, a o kẹgàn rẹ̀ patapata.
8 Awa ni arabirin kekere kan, on kò si
ni ọmú: kili awa o ṣe fun arabirin wa li
ọjọ ti a o ba fẹ ẹ?
9 Bi on ba ṣe ogiri, awa o kọ́ ile-odi fada-
ka le e lori: bi on ba si ṣe ẹnu-ọ̀na, awa o
fi apako kedari dí i.
10 Ogiri ni mi, ọmú mi sì dabi ile-
iṣọ: nigbana loju rẹ̀ mo dabi ẹniti o ri
alafia.
11 Solomoni ni ọgba-àjara kan ni Baal-
hamoni; o fi ọgba-àjara na ṣe ọ̀ya fun awọn
oluṣọ; olukuluku ni imu ẹgbẹrun fadaka
wá nipò eso rẹ̀.
12 Ọgba-àjara mi, ti iṣe temi, o wà ni-
waju mi: iwọ Solomoni yio ni ẹgbẹrun
fadaka, ati awọn ti nṣọ eso na yio ni igba.
13 Iwọ ti ngbe inu ọgbà, awọn ẹgbẹ rẹ
fetisi ohùn rẹ: mu mi gbọ́ ọ pẹlu.
14 Yara, olufẹ mi, ki iwọ ki o si dabi
abo egbin tabi ọmọ agbọnrin lori òke õrùn
didùn.

---

IWE WOLI

# ISAIAH.

## ORI 1.

IRAN Isaiah ọmọ Amosi, ti o rí nipa
Juda ati Jerusalemu li ọjọ Ussiah,
Jotamu, Ahasi, ati Hesekiah, awọn ọba
Juda.
2 Gbọ́, enyin ọrun, si fi eti silẹ, iwọ
aiye: nitori Oluwa ti sọ̀rọ, emi ti bọ́,
emi si tọ́ awọn ọmọ, nwọn si ti ṣọ̀tẹ si
mi.
3 Malũ mọ̀ oluwa rẹ̀, kẹtẹ́kẹtẹ si mọ̀
ibujẹ oluwa rẹ̀: ṣugbọn Israeli kò mọ̀,
awọn enia mi kò ronu.
4 A! orilẹ-ède ti o kún fun ẹ̀ṣẹ, enia
ti ẹrù ẹ̀ṣẹ npa, irú awọn oluṣe buburu, awọn
ọmọ ti iṣe olubajẹ: nwọn ti kọ̀ Oluwa silẹ,
nwọn ti mu Ẹni-Mimọ́ Israeli binu, nwọn
si ti yipada sẹhin.
5 Ẽṣe ti a o fi lù nyin si i mọ? ẹnyin o
ma ṣọ̀tẹ siwaju ati siwaju: gbogbo ori li o
ṣaisàn, gbogbo ọkàn li o si dakú.
6 Lati atẹlẹsẹ titi fi de ori kò si ilera
ninu rẹ̀; bikòṣe ọgbẹ́, ipalara, ati õju ti
nrà: nwọn kò iti pajumọ, bẽni a kò iti dì
wọn, bẽni a kò si ti ifi ororo kùn wọn.
7 Ilẹ nyin di ahoro, a fi iná kun ilu

Digitized by Google

nyin: ilẹ nyin, alejo jẹ ẹ run li oju nyin,
o si di ahoro, bi eyiti awọn alejo wó palẹ.
8 Ọmọbirin Sioni li a si fi silẹ bi agọ
ninu ọgbà àjara, bi abule ninu ọgbà apála,
bi ilu ti a dóti.
9 Bikòṣe bi Oluwa awọn ọmọ-ogun ti fi
iyokù diẹ kiun silẹ fun wa, awa iba ti dabi
Sodomu, awa iba si ti dabi Gomorra.
10 Gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, ẹnyin olori Sodo-
mu; fi eti si ofin Ọlọrun wa, ẹnyin enia
Gomorra.
11 Oluwa ni, kini ọ̀pọlọpọ ẹbọ nyin jasi
fun mi? emi kún fun ọrẹ sisun agbò, ati
fun ọrá ẹran abọ́pa; bẽni emi kò si ni inu
didùn si ẹjẹ akọ malũ, tabi si ti ọdọ-agutan,
tabi si ti obúkọ.
12 Nigbati ẹnyin wá lati fi ara'hàn ni-
waju mi, tali o bere eyi lọwọ nyin, lati tẹ̀
agbalá mi?
13 Ẹ má mu ọrẹ asan wá mọ́: turari
jasi ohun irira fun mi; oṣù titun ati ọjọ
isimi, ìpe ajọ, emi kò le rọju gbà; ẹ̀ṣẹ ni,
ani apẹ̀jọ ọ̀wọ ni.
14 Oṣù titun nyin ati ajọ ìdasilẹ nyin,
ọkàn mi korira; nwọn jasi iyọlẹnu fun
mi; o sú mi lati gbà wọn.
15 Nigbati ẹnyin si nà ọwọ́ nyin jade,
emi o pa oju mi mọ fun nyin: nitõtọ, ni-
gbati ẹnyin ba gbà adura pupọ̀, emi kì yio
gbọ́: ọwọ́ nyin kún fun ẹ̀jẹ.
16 Ẹ wẹ̀, ki ẹ mọ́; mu buburu iṣe nyin
kuro niwaju oju mi: dawọ duro lati ṣe
buburu;
17 Kọ́ lati ṣe rere; wá idajọ, ràn awọn
ẹniti anilara lọwọ, ṣe idajọ alainibaba,
gbà ẹjọ opó wi.
18 Oluwa wipe, wá nisisiyi, ki ẹ si jẹ ki
a sọ asọyé pọ̀: bi ẹ̀ṣẹ nyin ba ri bi òdodó,
nwọn o si fun bi òjo-didì; bi nwọn pọ́n bi
àlãri, nwọn o dabi irun-agutan.
19 Bi ẹnyin ba fẹ́ ti ẹ si gbọran, ẹnyin o
jẹ ire ilẹ na:
20 Ṣugbọn bi ẹnyin ba kọ̀, ti ẹ si ṣọ̀tẹ, a
o fi idà run nyin: nitori ẹnu Oluwa li o ti
wi i.
21 Ilu otitọ ha ti ṣe di àgbere! o ti kún
fun idajọ ri; ododo ti gbe inu rẹ̀ ri; ṣu-
gbọn nisisiyi, awọn apania.
22 Fadaka rẹ ti di ìdarọ́, ọti-waini rẹ ti
dà lu omi:
23 Awọn ọmọ-alade rẹ di ọlọ̀tẹ, ati ẹgbẹ
olè: olukuluku nfẹ́ ọrẹ, o si ntọ̀ erè lẹhin:
nwọn kò ṣe idajọ alainibaba, bẽni ọ̀ran opó
kò wá sọdọ wọn.
24 Nitorina Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-
ogun, Ẹni alagbara Israeli, wipe, Á, emi o
fi aiya balẹ niti awọn ọtá mi, emi o si
gbẹ̀san lara awọn ọtá mi.
25 Emi o yi ọwọ́ mi si ara rẹ, emi o si
yọ́ ìdarọ́ rẹ kuro patapata, emi o si mu
gbogbo tanganran rẹ kuro:
26 Emi o si mu awọn onidajọ rẹ pada bi
igbà iṣãju, ati awọn igbìmọ rẹ bi igbà akọ-
bẹrẹ: lẹhin na, a o pè ọ ni, Ilu ododo, ilu
otitọ.
27 Idajọ li a o fi rà Sioni pada, ati awọn
ti o pada bọ̀ nipa ododo.
28 Iparun awọn alarekọja pẹlu awọn
ẹlẹṣẹ yio wà pọ̀, ati awọn ti o kọ̀ Oluwa
silẹ li a o parun.
29 Nitoriti oju yio tì wọn niti igi-nla ti
ẹnyin ti fẹ, a o si dãmu nyin niti ọgbà ti
ẹnyin ti yàn.
30 Nitori ẹnyin o dabi igi-nla ti ewe rẹ̀
rọ, ati bi ọgbà ti kò ni omi.
31 Alagbara yio si dabi lẹwù, iṣẹ rẹ̀ yio
si dabi ẹta-iná, ati awọn mejeji yio jọ jona
pọ̀, ẹnikẹni kì yio si pa wọn.

## ORÍ 2.

ỌRỌ ti Isaiah ọmọ Amosi ri nipa Juda
ati Jerusalemu.
2 Yio si ṣe ni ọjọ ikẹhìn, a o fi òke ile
Oluwa kalẹ lori awọn òke nla, a o si gbe e
ga ju awọn òke kékèké lọ; gbogbo orilẹ-
ède ni yio si wọ́ si inu rẹ̀.
3 Ọ̀pọlọpọ enia ni yio si lọ, nwọn o si
wipe, Ẹ wá, ẹ jẹ ki a lọ si òke Oluwa, si
ile Ọlọrun Jakobu; On o si kọ́ wa li ọ̀na
rẹ̀, awa o si ma rìn ni ipa rẹ̀; nitori lati
Sioni ni ofin yio ti jade lọ, ati ọ̀rọ Oluwa
lati Jerusalemu.
4 On o si dajọ lãrin awọn orilẹ-ède, yio
si ba ọ̀pọlọpọ enia wi: nwọn o fi idà wọn
rọ ọbẹ-plau, nwọn o si fi ọ̀kọ wọn rọ dojé;
orilẹ-ède kì yio gbe idà soke si orilẹ-ède;
bẽni nwọn kì yio kọ́ ogun jijà mọ.
5 Ara ile Jakobu, ẹ wá, ẹ jẹ́ ka rìn ninu
imọlẹ Oluwa.
6 Nitorina ni iwọ ṣe kọ̀ awọn enia rẹ
ile Jakobu silẹ̀; nitoriti nwọn kún lati ìla-
õrùn wá, nwọn jẹ alafọ̀ṣẹ bi awọn ara Fi-
listea, nwọn si nṣe inu didùn ninu awọn
ọmọ alejò.
7 Ilẹ wọn pẹlu kún fun fadakà ati wurà;
bẽni kò si opin fun iṣura wọn; ilẹ wọn si
kun fun ẹṣin, bẽni kò si opin fun kẹkẹ́
ogun wọn.
8 Ilẹ wọn kún fun oriṣa pẹlu; nwọn
mbọ iṣẹ ọwọ́ ara wọn, eyiti ika awọn
tikalawọn ti ṣe.

Digitized by Google

9 Enia lasan si foribalẹ, ẹni-nla si rẹ̀ ara
rẹ̀ silẹ; nitorina má ṣe dariji wọn.
10 Wọ̀ inu apata lọ, ki o si fi ara rẹ
pamọ ninu ekuru, nitori ibẹru Oluwa, ati
nitori ogo ọlanla rẹ̀.
11 A o rẹ̀ ìwo giga enia silẹ, a o si tẹ̀
ori igberaga enia ba, Oluwa nikansọsọ li
a o gbe ga li ọjọ na.
12 Nitori ọjọ Oluwa awọn ọmọ-ogun yio
wà lori olukuluku ẹniti o rera, ti o si
gberaga, ati lori olukuluku ẹniti a gbe
soke, on li a o si rẹ̀ silẹ.
13 Lori gbogbo igi kedari Lebanoni, ti
o ga, ti a si gbe soke, ati lori gbogbo igi-
nla Baṣani.
14 Ati lori gbogbo òke giga, ati lori
gbogbo òke kékèké ti a gbe soke.
15 Ati lori gbogbo ile-iṣọ giga ati lori
gbogbo odi,
16 Ati lori gbogbo ọkọ̀ Tarṣiṣi, ati lori
gbogbo awòran ti o wuni,
17 A o si tẹ̀ ori igberaga enia balẹ, irera
awọn enia li a o si rẹ̀ silẹ; Oluwa nikanṣoṣo
li a o gbega li ọjọ na.
18 Awọn òriṣa ni yio si parun patapata.
19 Nwọn o si wọ̀ inu ihò apata lọ, ati
inu ihò ilẹ, nitori ìbẹru Oluwa, ati nitori
ogo ọlanla rẹ̀, nigbati o ba dide lati mì ilẹ
aiye kijikiji.
20 Li ọjọ na, enia yio jù òriṣa fadakà
rẹ̀, ati òriṣa wurà rẹ̀, ti nwọn ṣe olukuluku
wọn lati ma bọ, si ekute ati si àdán,
21 Lati lọ sinu pàlapala apata, ati soke
apata sisán, nitori ibẹru Oluwa, ati nitori
ogo ọlanla rẹ̀; nigbati o ba dide lati mì ilẹ
aiye kijikiji.
22 Ẹ simi lẹhìn enia, ẹmi ẹniti o wà ni
ihò imu rẹ̀; nitori ninu kini a le kà a si?

ORI 3.

KIYESI I, Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-
ogun, mu idaduro ati ọpá kuro ninu
Jerusalemu ati Juda, gbogbo idaduro onjẹ,
ati gbogbo idaduro omi.
2 Alagbara ọkọnrin, ati jagunjagun, oni-
dajọ, ati wolĩ, ati amoye, ati agbà.
3 Balogun ãdọta, ati ọkọnrin ọlọla, ati
igbìmọ, ati onìṣọ̀na, ati alasọdùn.
4 Awọn ọmọde li emi o fi ṣe ọmọ-alade
wọn, awọn ọmọ-ọwọ ni yio si ma ṣe akoso
wọn.
5 A o si ni awọn enia lara, olukuluku
lọwọ ẹnikeji, ati olukuluku lọwọ aladugbo
rẹ̀; ọmọde yio huwà igberaga si àgba, ati
alailọla si ọlọla.
6 Nigbati enia kan yio di arakọnrin rẹ̀
ti ile baba rẹ̀ mu, wipe, Iwọ ni aṣọ, mã ṣe
alakoso wa, ki o si jẹ ki iparun yi wà
labẹ ọwọ́ rẹ.
7 Lọjọ na ni yio bura, wipe, Emi ki
yio ṣe alatunṣe: nitori ni ile mi kò si onjẹ
tabi aṣọ: máṣe fi emi ṣe alakoso awọn enia.
8 Nitori Jerusalemu di iparun, Juda si
ṣubu: nitori ahọn wọn ati iṣe wọn lòdi si
Oluwa, lati mu oju ogo rẹ̀ binu.
9 Iwò oju wọn njẹri si wọn; nwọn si nfi
ẹ̀ṣẹ wọn hàn bi Sodomu, nwọn kò pa a mọ.
Egbe ni fun ọkàn wọn! nitori nwọn ti fi
ibi san a fun ara wọn.
10 Ẹ sọ fun olododo pe, yio dara fun u:
nitori nwọn o jẹ eso iṣe wọn.
11 Egbe ni fun enia buburu! yio buru
fun u: nitori ere ọwọ́ rẹ̀ li a o fi fun u.
12 Niti awọn enia mi awọn ọmọde ni
aninilara wọn, awọn obirin si njọba wọn.
A! enia mi, awọn ti nyẹ ọ si mu ọ ṣina,
nwọn si npa ipa-ọ̀na-rẹ run.
13 Oluwa dide duro lati wijọ, o si dide
lati da awọn enia li ẹjọ.
14 Oluwa yio ba awọn agbà enia rẹ̀ lọ
sinu idajọ, ati awọn ọmọ-alade inu wọn:
nitori ẹnyin ti jẹ ọ̀gba àjara nì run: ẹrù
awọn talakà mbẹ ninu ile nyin.
15 Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-ogun wipe,
Kili ẹnyin rò ti ẹ fi fọ́ awọn enia mi tutu,
ti ẹ si fi oju awọn talakà rinlẹ?
16 Pẹlupẹlu Oluwa wipe, Nitori awọn
ọmọbirin Sioni gberaga, ti nwọn si nrin
pẹlu ọrùn giga ati oju ifẹkufẹ, ti nwọn nrin
ti nwọn si nyan bi nwọn ti nlọ, ti nwọn si
njẹ ki ẹsẹ wọn ró woro:
17 Nitorina Oluwa yio fi ẽpá lu atàri
awọn ọmọbirin Sioni, Oluwa yio si fi ihoho
wọn hàn.
18 Li ọjọ na Oluwa yio mu ogo ṣaworo
wọn kuro, ati awọn ọṣọ́ wọn, ati iweri wọn
bi oṣupa.
19 Ati ẹ̀wọn, ati jufù, ati ìboju,
20 Ati akẹtẹ̀, ati ohun ọṣọ-ẹsẹ, ati ọjá-
ori, ati ago olõrùn didùn, ati oruka eti,
21 Oruka, ati ọṣọ́-imu,
22 Ipãrọ̀ aṣọ wiwọ̀, ati aṣọ ilekè, ati
ibòrun, ati àpo,
23 Awòjiji, ati aṣọ ọ̀gbọ daradara, ati
ibòri ati ibòju,
24 Yio si ṣe pe, õrun buburu yio wà
dipò õrun didùn; akisà ni yio si dipò
amùre; ori pipá ni yio si dipò irun didì
daradara; sisan aṣọ ọ̀fọ dipò igbaiya, ijoná
yio si dipò ẹwà.
25 Awọn ọkọnrin rẹ yio ti ipa idà ṣubu,
ati awọn alagbara rẹ loju ogun.

Digitized by Google

26 Awọn bodè rẹ̀ yio pohùnrere ẹkun, nwọn o si ṣọ̀fọ; ati on, nitori o di ahoro, yio joko ni ilẹ.

## ORI 4.

ATI li ọjọ na obirin meje yio dimọ́ ọkọnrin kan, wipe, Awa o jẹ onjẹ ara wa, awa o si wọ̀ aṣọ ara wa: nikan ni, jẹ ki a fi orukọ rẹ pè wa, lati mu ẹgàn wa kuro.

2 Li ọjọ na ni ẹka Oluwa yio ni ẹwà on ogo, eso ilẹ yio si ni ọla, yio si dara fun awọn ti o sálà ni Israeli.

3 Yio si ṣe, pe, ẹniti a fi silẹ ni Sioni, ati ẹniti o kù ni Jerusalemu, li a o pè ni mimọ́, ani orukọ olukuluku ẹniti a kọ pẹlu awọn alãye ni Jerusalemu.

4 Nigbati Oluwa ba ti wẹ̀ ẹgbin awọn ọmọbirin Sioni nù, ti o si ti fọ ẹ̀jẹ Jerusalemu kuro li ãrin rẹ̀ nipa ẹmi idajọ, ati nipa ẹmi ijoná.

5 Lori olukuluku ibùgbe oke Sioni, ati lori awọn apejọ rẹ̀, li Oluwa yio si da awọsanma, ati ẽfin li ọsan, ati didan ọwọ́ iná li oru: nitori àbò yio wà lori gbogbo ogo.

6 Agọ kan yio si wà fun ojiji li ọsan kuro ninu oru, ati fun ibi isasi, ati fun ãbo kuro ninu ijì, ati kuro ninu ojò.

## ORI 5.

NISISIYI, emi o kọ orin si olufẹ ọwọ́n mi, orin olùfẹ mi ọwọ́n niti ọ̀gba àjara rẹ̀. Olufẹ ọwọ́n mi ni ọ̀gba àjara lori okè ẹlẹtù loju:

2 O si sọ ọ̀gba yi i ka, o si ṣà okuta kuro ninu rẹ̀, o si gbìn ayànfẹ àjara si inu rẹ̀, o si kọ ile iṣọ sãrin rẹ̀, o si ṣe ifunti sinu rẹ̀ pẹlu: o si wò pe ki o so eso, ṣugbọn eso kikan li o so.

3 Njẹ nisisiyi, ẹnyin ara Jerusalemu ati ẹnyin ọkọnrin Juda, emi bẹ̀ nyin, ṣe idajọ lãrin mi, ati lãrin ọ̀gba àjara mi.

4 Kini a ba ṣe si ọ̀gba àjara mi ti emi kò ti ṣe ninu rẹ̀, nigbati mo wò pe iba so eso, ẽṣe ti o fi so eso kikan.

5 Njẹ nisisiyi, ẹ wá na, emi o sọ ohun ti emi o ṣe si ọ̀gba àjara mi fun nyin: emi o mu ọ̀gba rẹ̀ kuro, a o si jẹ ẹ run, emi o wo ogiri rẹ̀ lu ilẹ, a o si tẹ̀ ẹ mọlẹ.

6 Emi o si sọ ọ di ahoro, a kì yio tọ́ ẹka rẹ̀, bẹ̃ni a kì yio wà a, ṣugbọn ẹ̀wọn ati ẹgún ni yio ma hù nibẹ, emi o si paṣẹ fun awọsanma ki o má rọjò sori rẹ̀.

7 Nitori ọ̀gba àjara Oluwa awọn ọmọogun ni ile Israeli, ati awọn ọkọnrin Juda ni igi-gbìgbin ti o wù u, o reti idajọ, ṣugbọn kiyesi i, inilara; o si reti ododo; ṣugbọn kiyesi i, igbe.

8 Egbe ni fun awọn ti o ni ile kún ile, ti nfi oko kún oko, titi àye kò fi si mọ, ki nwọn bà le nikan wà li ãrin ilẹ aiye!

9 Li eti mi ni Oluwa awọn ọmọ-ogun sọ pe, Nitõtọ ọ̀pọ ile ni yio di ahoro, ile nla ati didara laisi olugbe.

10 Nitõtọ ìwọn akeri mẹwa ọ̀gba àjara yio mu òṣuwọn bati kan wá, ati òṣuwọn irugbìn homeri kan yio mu òṣuwọn efa kan wá.

11 Egbe ni fun awọn ti ima dide ni kùtukutu, ki nwọn le ma lepa ọti lile; ti nwọn wà ninu rẹ̀ titi di alẹ, titi ọti-waini mu ara wọn gbona!

12 Ati durù, ati fioli, tabreti, ferè, ati ọti-waini wà ninu àse wọn: ṣugbọn nwọn kò kà iṣẹ Oluwa si, bẹ̃ni nwọn kò rò iṣẹ ọwọ́ rẹ̀.

13 Nitorina awọn enia mi lọ si oko-ẹru, nitoriti oye kò si, awọn ọlọla wọn di rirù, ati ọ̀pọlọpọ wọn gbẹ fun orùngbẹ.

14 Nitorina ipò-okú ti fun ara rẹ̀ li àye, o si là ẹnu rẹ̀ li aini ìwọn: ati ogo wọn, ati ọ̀pọlọpọ wọn, ati ọṣọ́ wọn, ati awọn ẹniti nyọ̀, yio sọkalẹ sinu rẹ̀.

15 Enia lasan li a o rẹ̀ silẹ, ati ẹni-alagbara li a o rẹ̀ silẹ, oju agberaga li a o si rẹ̀ silẹ.

16 Ṣugbọn Oluwa awọn ọmọ-ogun li a o gbe ga ni idajọ, ati Ọlọrun Ẹni-Mimọ́ yio jẹ mimọ́ ninu ododo.

17 Nigbana li awọn ọdọ-agutan yio ma jẹ̀ gẹgẹ bi iṣe wọn, ati ibi ahoro awọn ti o sanra li awọn alejò yio ma jẹ.

18 Egbe ni fun awọn ti nfi ohùn asan fà ìwa buburu, ati awọn ti o dabi ẹnipe nfi okùn kẹkẹ́ fà ẹ̀ṣẹ.

19 Awọn ti o wipe, Jẹ ki o yara, ki o si mu iṣẹ rẹ̀ yara, ki awa ki o le ri i: ati jẹ ki ìmọ Ẹni-Mimọ́ Israeli sunmọ ìhin, ki o si wá, ki awa ki o le mọ̀ ọ.

20 Egbe ni fun awọn ti npè ibi ni rere, ati rere ni ibi, ti nfi okùnkun ṣe imọlẹ, ati imọlẹ ṣe okùnkun: ti nfi ikorò pe adùn, ati adùn pe ikorò!

21 Egbe ni fun awọn ti nwọn gbọ́n li oju ara wọn, ti nwọn si mọ̀ oye li oju ara wọn!

22 Egbe ni fun awọn ti o ni ipá lati mu ọti-waini, ati awọn ọkọnrin alagbara lati ṣe adàlu ọti lile:

23 Awọn ẹniti o da are fun ẹni-buburu nitori ère, ti nwọn si mu ododo olododo kuro li ọwọ́ rẹ̀.

Digitized by Google

24 Nitorina bi iná ti ijo akekù koriko
run, ti ọwọ́ iná si ijo iyàngbo; bẹ̃ni egbò
wọn yio dabi rirà: itana wọn yio si gòke
bi ekuru; nitori nwọn ti ṣá ofin Oluwa
awọn ọmọ-ogun tì, nwọn si ti gàn ọ̀rọ Ẹni-
Mimọ Israeli.
25 Nitorina ni ibinu Oluwa fi ràn si
enia rẹ̀, o si ti na ọwọ́ rẹ̀ si wọn, o si ti lù
wọn: awọn òke si warìri, okú wọn si wà
bi igbẹ li ãrin igboro. Ni gbogbo eyi
ibinu rẹ̀ kò yi kuro, ṣugbọn ọwọ́ rẹ̀ nà jade
sibẹ.
26 Yio si gbe ọpágun soke si awọn orilẹ-
ède ti o jìna, yio si kọ si wọn lati opin ilẹ
wá, si kiyesi i, nwọn o yara wá kánkán.
27 Kò si ẹniti yio rẹ̀, tabi ti yio kọsẹ
ninu wọn, kò si ẹniti yio tõgbe tabi ti yio
sùn: bẹ̃ni amùre ẹgbẹ wọn kì yio tu, bẹ̃ni
okùn bàta wọn kì yio ja.
28 Awọn ẹniti ọfà wọn mu, ti gbogbo
ọrun wọn si kàn, a o ka patakò ẹsẹ ẹṣin
wọn si okuta akọ, ati kẹkẹ́ wọn bi ãja.
29 Kike wọn yio dabi ti kiniun, nwọn o
ma ke bi awọn ọmọ kiniun, nitõtọ nwọn o
ma ke, nwọn o si di ohun ọdẹ na mu, nwọn
a si gbe e lọ li ailewu, kò si ẹnikan ti yio
gbà a.
30 Ati li ọjọ na nwọn o ho si wọn, bi
hiho okun: bi ẹnikan ba si wo ilẹ na,
kiyesi i, okùnkun ati ipọnju, imọlẹ si di
okùnkun ninu awọsanma dudu rẹ̀.

## ORI 6.

LI ọdun ti Ussiah ọba kú, emi ri Oluwa
joko lori itẹ ti o ga, ti o si gbe ara
soke, iṣẹti aṣọ igunwà rẹ̀ kun tempili.
2 Awọn serafu duro loke rẹ̀: ọkọkan
wọn ni iyẹ mẹfa, o fi meji bò oju rẹ̀, o si fi
meji bò ẹsẹ rẹ̀, o si fi meji fò.
3 Ikini si ke si ekeji pe, Mimọ́, mimọ́,
mimọ́, li Oluwa awọn ọmọ-ogun, gbogbo
aiye kún fun ogo rẹ̀.
4 Awọn òpo ilẹ̀kun si mì nipa ohùn ẹniti
o ke, ile na si kún fun ẽfin.
5 Nigbana ni mo wipe, Egbe ni fun mi,
nitori mo gbé, nitoriti mo jẹ́ ẹni-alaimọ́
etè, mo si wà lãrin awọn enia alaimọ́ etè,
nitoriti oju mi ti ri Ọba, Oluwa awọn ọmọ-
ogun.
6 Nigbana ni ọkan ninu awọn serafu fò
wá sọdọ mi, o ni ẹṣẹ́-iná li ọwọ́ rẹ̀, ti o ti fi
ẹmú mu lati ori pẹpẹ wá.
7 O si fi kàn mi li ẹnu, o si wipe, Kiyesi
i, eyi ti kàn etè rẹ, a mu aiṣedede rẹ kuro,
a si fọ ẹ̀ṣẹ rẹ nù.
8 Emi si gbọ́ ohùn Oluwa pẹlu wipe,
Tali emi o rán, ati tani o si lọ fun wa?
Nigbana li emi wipe, Emi nĩ; rán mi.
9 On si wipe, Lọ, ki o si wi fun awọn
enia yi, Ni gbigbọ́, ẹ gbọ́, ṣugbọn oye ki
yio ye nyin; ni riri, ẹ ri, ṣugbọn ẹnyin ki
yio si mọ̀ oye.
10 Mu ki aiya awọn enia yi ki o sebọ, si
mu ki eti wọn ki o wuwo, ki o si di wọn li
oju, ki nwọn ki o má ba fi eti wọn gbọ́, ki
nwọn ki o má ba fi ọkàn wọn mọ̀, ki nwọn
ki o má ba yipada, ki a má ba mu wọn li
ara dá.
11 Nigbana ni emi wipe, Oluwa, yio ti
pẹ to? O si dahùn pe, Titi awọn ilu-nla yio
fi di ahoro, li aisi olugbe, ati awọn ile li
aisi enia, ati ilẹ yio di ahoro patapata.
12 Titi Oluwa yio fi ṣi awọn enia na
kuro lọ réré, ti ikọ̀silẹ nla yio si wà ni inu
ilẹ na.
13 Ṣugbọn sibẹ, idamẹwa yio wà ninu
rẹ̀, yio si padà, yio si di rirun, bi igi teili,
ati bi igi oakù eyiti ọpá wà ninu wọn, ni-
gbati ewe wọn ba rẹ̀: bẹ̃ni iru mimọ́ na
yio jẹ ọpá ninu rẹ̀.

## ORI 7.

O SI ṣe li ọjọ Ahasi ọmọ Jotamu ọmọ
Ussiah, ọba Juda, ti Resini, ọba Siria,
ati Peka ọmọ Remaliah, ọba Israeli, gokè
lọ si Jerusalemu lati jà a li ogun, ṣugbọn
nwọn kò le bori rẹ̀.
2 A si sọ fun ile Dafidi pe, Siria ba
Efraimu dìmọlú. Ọkàn rẹ̀ si mì, ati okàn
awọn enia rẹ̀ bi igi igbo ti imì nipa ẹfũfu.
3 Oluwa si sọ fun Isaiah pe, Jade nisisiyi,
lọ ipade Ahasi, iwọ, ati Ṣeajaṣubu ọmọ rẹ,
ni ipẹkun oju iṣàn ikudu ti apa oke, li
opopo pápa afọṣọ;
4 Si sọ fun u pe, Kiyesara, ki o si gbe jẹ,
má bẹru, bẹ̃ni ki o máṣe jaiya nitori iru
meji igi iná ti nrú ẽfin wọnyi nitori ibinu
mimuna Resini pẹlu Siria, ati ti ọmọ Re-
maliah.
5 Nitori Siria, Efraimu, ati ọmọ Rema-
liah ti gbìmọ ibi si ọ wipe,
6 Ẹ jẹ ki a gòke lọ si Juda, ki a si bà a
ninu jẹ, ẹ si jẹ ki a ṣe ihò ninu rẹ̀ fun ara
wa, ki a si gbe ọba kan kalẹ lãrin rẹ̀, ani
ọmọ Tabeali:
7 Bayi ni Oluwa Jehofah wi, Ìmọ na kì
yio duro, bẹ̃ni ki yio ṣẹ.
8 Nitori ori Siria ni Damasku, ori
Damasku si ni Resini; ninu ọdun ma-
runlelọgọta li a o fọ Efraimu ti ki yio si jẹ́
enia mọ.
9 Ori Efraimu si ni Samaria, ori Samaria

Digitized by Google

si ni ọmọ Remaliah. Bi ẹnyin ki yio ba
gbagbọ́, lotitọ, a ki yio fi idi nyin mulẹ.
10 Oluwa si tun sọ fun Ahasi pe,
11 Bere àmi kan lọwọ Oluwa Ọlọrun rẹ ;
bere rẹ̀, ibã jẹ ni ọgbun tabi li okè.
12 Ṣugbọn Ahasi wipe, Emi ki yio bere,
bẽni emi ki yio dán Oluwa wò.
13 On si wipe, Ẹ gbọ́ nisisiyi ẹnyin ara
ile Dafidi, iṣe ohun kekere fun nyin lati
dá enia lagara, ṣugbọn ẹnyin o ha si dá
Ọlọrun mi lagara pẹlu bi?
14 Nitorina, Oluwa tikalarẹ̀ yio fun
nyin li àmi kan, Kiyesi i, Wundia kan yio
loyun, yio si bi ọmọkọnrin kan, yio si pe
orukọ rẹ̀ ni Immanueli.
15 Ori-amọ ati oyin ni yio ma jẹ, ki o le
ba mọ̀ bi ãti kọ̀ ibi, ãti bi ãti yàn ire.
16 Nitoripe, ki ọmọ na ki o to mọ̀ bi
ãti kọ̀ ibi, ati bi ãti yàn ire, ilẹ ti iwọ
korira yio di ikọ̀silẹ lọdọ ọba rẹ̀ mejeji.
17 Oluwa yio si mu ọjọ ti kò si bẹ̃ ri wá
sori rẹ ati sori awọn enia rẹ, ati sori ile
baba rẹ, lati ọjọ ti Efraimu ti lọ kuro lọdọ
Juda, ani ọba Assiria.
18 Yio si ṣẹ li ọjọ na, Oluwa yio kọ si
eṣinṣin ti o wà li apa ipẹkun odo ṣiṣàn
nlanla Egipti, ati si oyin ti o wà ni ilẹ
Assiria.
19 Nwọn o si wá, gbogbo wọn o si bà
sinu afonifojì ijù, ati sinu pàlapàla okuta,
ati lori gbogbo ẹgun, ati lori eweko gbogbo.
20 Li ọjọ kanna ni Oluwa yio fi abẹ ti a
yá, eyini ni, awọn ti ihà keji odo nì, ọba
Assiria, fá ori ati irun ẹsẹ, yio si run irun-
gbọn pẹlu.
21 Yio si ṣẹ li ọjọ na, enia kan yio si tọ́
ọmọ malu kan ati agutan meji;
22 Yio si ṣẹ, nitori ọ̀pọlọpọ wàra ti nwọn
o mu wá, yio ma jẹ ori-amọ; nitori ori-
amọ ati oyin ni olukulùku ti o ba kù ni
ãrin ilẹ na yio ma jẹ.
23 Yio si ṣẹ li ọjọ na, ibi gbogbo yio ri
bayi pe, ibi ti ẹgbẹrun àjara ti wà fun
ẹgbẹrun owo fadakà yio di ti ẹwọn ati ẹgun.
24 Pẹlu ọfà ati ọrun ni enia yio wá ibẹ,
nitoripe gbogbo ilẹ na yio di ẹwọn ati ẹgun.
25 Ati lori gbogbo okè kékèké ti a o fi
ọkọ́ tu, ẹ̀ru ẹ̀wọn ati ẹ̀gun ki yio de ibẹ̀:
ṣugbọn yio jẹ ilu ti a ndà malũ lọ, ati ibi
itẹ̀mọlẹ fun awọn ẹran kékèké.

## ORI 8.

PẸLUPẸLU Oluwa wi fun mi pe, Iwọ
mu iwe nla kan, ki o si fi kalamu enia
kọwe si inu rẹ̀ niti Maher-ṣalal-haṣ-basi.
2 Emi si mu awọn ẹlẹri otitọ sọdọ mi
lati ṣe ẹlẹri. Uriah alufa, ati Sekeriah
ọmọ Jeberekiah.
3 Mo si wọle tọ wolĩ obirin nì lọ; o si
loyun o si bi ọmọkọnrin kan. Nigbana ni
Oluwa wi fun mi pe, sọ orukọ rẹ̀ ni Maher-
ṣalal-haṣ-basi.
4 Nitoripe ki ọmọ na to ni oye ati ke
pe, Baba mi, ati iya mi, ọrọ̀ Damasku ati
ikogun Samaria ni a o mu kuro niwaju ọba
Assiria.
5 Oluwa si tun wi fun mi pe,
6 Niwọn bi enia yi ti kọ̀ omi Ṣiloa ti
nṣàn jẹjẹ silẹ, ti nwọn si nyọ̀ ninu Resini
ati ọmọ Remaliah.
7 Njẹ nitorina kiyesi i, Oluwa nfà omi
odò ti o le, ti o si pọ̀, wá sori wọn, ani ọba
Assiria ati gbogbo ogo rẹ̀; yio si wá sori
gbogbo ọ̀na odò rẹ̀, yio si gun ori gbogbo
bèbe rẹ̀.
8 Yio si kọja li arin Juda; yio si ṣàn bò
o mọlẹ, yio si mù u de ọrùn, ninà iyẹ rẹ̀ yio
si kún ibú ilẹ rẹ, iwọ Immanueli.
9 Ẹ ko ara nyin jọ, ẹnyin enia, a o si fọ
nyin tũtu: ẹ si fi eti silẹ, gbogbo ẹnyin ara
ilẹ jijìna: ẹ di ara nyin li àmure, a o si fọ
nyin tũtu; ẹ di ara nyin li àmure, a o si
fọ nyin tũtu.
10 Ẹ gbìmọ pọ̀ yio si di asan; ẹ sọ̀rọ na,
ki yio si duro: nitoripe Ọlọrun wà pẹlu
wa.
11 Nitoriti Oluwa wi bayi fun mi, nipa
ọwọ agbara, o si kọ mi ki nmá ba rìn ni
ọ̀na enia yi, pe,
12 Ẹ máṣe pè gbogbo eyi ni imulẹ ti
awọn enia yi pè ni imulẹ: bẽni ẹ máṣe
bẹ̀ru ibẹ̀ru wọn, ẹ má si ṣe foya.
13 Yà Oluwa awọn ọmọ-ogun tikalarẹ̀ si
mimọ́; si jẹ ki o ṣe ẹ̀ru nyin, si jẹ ki o ṣe
ifòya nyin.
14 On o si wà fun ibi mimọ́, ṣugbọn fun
okuta idùgbolu, ati fun apata ẹ̀ṣẹ, si ile
Israeli mejeji, fun ẹgẹ, ati fun okùn didẹ
si awọn ara Jerusalemu.
15 Ọ̀pọlọpọ ninu wọn yio si kọsẹ, nwọn
o si ṣubu, a o si fọ wọn, a o si mu wọn.
16 Di ẹri na, fi edídi di ofin na lãrin
awọn ọmọ-ẹhin mi.
17 Emi o si duro de Oluwa, ti o pa oju
rẹ̀ mọ kuro lara ile Jakobu, emi o si ma wo
ọ̀na rẹ̀.
18 Kiyesi i, emi ati awọn ọmọ ti Oluwa
ti fi fun mi wà fun àmi ati fun iyanu ni
Israeli, lati ọdọ Oluwa awọn ọmọ-ogun wá,
ti ngbe òke Sioni.
19 Nigbati nwọn ba si wi fun nyin pe,
Ẹ wá awọn ti mba okú lò, ati awọn oṣó ti

Digitized by Google

nke, ti nsi nkùn, kò ha yẹ ki orilẹ-ède ki
o wá Ọlọrun wọn jù ki awọn alãye ma wá
awọn okú?
20 Si ofin ati si ẹri: bi nwọn kò ba sọ
gẹgẹ bi ọ̀rọ yi, nitoriti kò si imọlẹ ninu
wọn ni.
21 Nwọn o si kọja lọ lãrin rẹ̀, ninu
inilara ati ebi: yio si ṣe pe nigbati ebi yio
pa wọn, nwọn o ma kanra, nwọn o si fi ọba
ati Ọlọrun wọn ré, nwọn o si ma wò òke.
22 Nwọn o si wò ilẹ, si kiyesi i, iyọnu
ati okùnkun, iṣuju irora: a o si le wọn lọ
sinu okùnkun.

## ORI 9.

SUGBỌN iṣuju na kì yio wà nibiti wahalà
mbẹ nisisiyi, gẹgẹ bi ìgba iṣãju ti mu
itìju wá si ilẹ Sebuloni ati ilẹ Naftali, bẽni
ìgba ikẹhin yio mu ọla wá si ọ̀na okun,
niha ẹkùn Jordani, Galili awọn orilẹ-ède.
2 Awọn enia ti nrìn li okùnkun ri imọlẹ
nla: awọn ti ngbe ilẹ ojiji ikú, lara wọn ni
imọlẹ mọ́ si.
3 Iwọ ti mu orilẹ-ède nì bi si i pupọ̀-
pupọ̀, iwọ si sọ ayọ̀ di pupọ̀ fun u: nwọn
nyọ̀ niwaju rẹ gẹgẹ bi ayọ̀ ikore, ati gẹgẹ bi
enia iti yọ̀ nigbati nwọn npin ikogun.
4 Nitori iwọ ṣẹ́ ajàga-irù rẹ̀, ati ọpá eji-
ka rẹ̀, ọgọ aninilara rẹ̀, gẹgẹ bi li ọjọ Midi-
ani.
5 Nitori gbogbo ihamọra awọn ologun
ninu irọ́kẹ̀kẹ, ati aṣọ ti a yi ninu ẹ̀jẹ, yio
jẹ fun ijoná ati igi iná.
6 Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọ-
kọnrin kan fun wa: ijọba yio si wà li ejika
rẹ̀: a o si ma pe orukọ rẹ̀ ni Iyanu, Oluda-
mọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye,
Ọmọ-Alade Alafia.
7 Ijọba yio bi si i, alafia ki yio ni ipẹ-
kun: lori itẹ Dafidi, ati lori ijọba rẹ̀, lati
ma tọ́ ọ, ati lati fi idi rẹ̀ mulẹ, nipa idajọ,
ati ododo lati isisiyi lọ, ani titi lai. Itara
Oluwa awọn ọmọ-ogun yio ṣe eyi.
8 Oluwa rán ọ̀rọ si Jakobu, o si ti bà lé
Israeli.
9 Gbogbo enia yio si mọ̀ ọ, Efraimu ati
awọn ti ngbe Samaria, ti nwi ninu igbera-
ga, ati lile aiya pe,
10 Briki wọnni ṣubu lu ilẹ, ṣugbọn awa
o fi okuta gbigbẹ́ mọ ọ: a ke igi sikamore
lu ilẹ, ṣugbọn a o fi igi kedari pãrọ̀ wọn.
11 Nitorina li Oluwa yio gbe awọn ani-
nilara Resini dide si i, yio si dá awọn ọtá
rẹ̀ pọ̀.
12 Awọn ara Siria niwaju, ati awọn Fi-
listini lẹhin: nwọn o si fi gbogbo ẹnu jẹ
Israeli run. Ni gbogbo eyi ibinu rẹ̀ kò yi
kuro, ṣugbọn ọwọ́ rẹ̀ nà jade sibẹ.
13 Awọn enia na kò yipada si ẹniti o lù
wọn, bẽni nwọn kò wá Oluwa awọn ọmọ-
ogun.
14 Nitorina ni Oluwa yio ke ori ati irù,
imọ̀-ọpẹ ati koriko-odò kuro ni Israeli, li
ọjọ kan.
15 Agbà ati ọlọla, on li ori, ati woli ti
nkọni li eké, on ni irù.
16 Nitori awọn olori enia yi mu wọn
ṣìna: awọn ti a si tọ́ li ọ̀na ninu wọn li a
parun.
17 Nitorina ni Oluwa kì yio ṣe ni ayọ̀
ninu ọdọ-ọmọkọnrin wọn, bẽni ki yio ṣãnu
fun awọn alainibaba ati opo wọn: nitori
olukuluku wọn jẹ agabagebe ati oluṣe-
buburu, olukuluku ẹnu nsọ wère. Ni gbo-
gbo eyi ibinu rẹ̀ kò yi kuro, ṣugbọn ọwọ́ rẹ̀
nà jade sibẹ.
18 Nitori ìwa-buburu njo bi iná: yio jo
ẹwọn ati ẹgún run, yio si ràn ninu pàntiri
igbó, nwọn o si goke lọ bi ẽfin iti goke.
19 Nipa ibinu Oluwa awọn ọmọ-ogun ni
ilẹ fi ṣõkùn, awọn enia yio dabi igi iná,
ẹnikan kì yio dá arakọnrin rẹ̀ si.
20 On o si jajẹ li ọwọ́ ọ̀tun, ebi o si pa
a; on o si jẹ li ọwọ́ osì; nwọn kì yio si yo:
olukuluku enia yio si jẹ ẹran-ara apá rẹ̀.
21 Manasse o jẹ Efraimu; Efraimu o si
jẹ Manasse: awọn mejeji o dojukọ Juda.
Ni gbogbo eyi, ibinu rẹ̀ kò yi kuro, ṣugbọn
ọwọ́ rẹ̀ nà jade sibẹ.

## ORI 10.

EGBE ni fun awọn ti npaṣẹ aiṣododo, ati
fun awọn akọwe ti nkọ iwe ìka;
2 Lati yi alaini kuro ni idajọ, ati lati mu
ohun ẹtọ kuro lọwọ talakà enia mi, ki awọn
opó ba le di ijẹ wọn, ati ki wọn ba le jà
alainibaba li ole!
3 Kili ẹnyin o ṣe lọjọ ibẹ̀wọ, ati ni ida-
horo ti yio ti okere wá? tali ẹnyin o sá tọ̀
fun irànlọwọ? nibo li ẹnyin o si fi ogo
nyin si?
4 Laisi emi nwọn o tẹ̀ ba labẹ awọn ara-
tubu, nwọn o si ṣubu labẹ awọn ti a pa.
Ni gbogbo eyi ibinu rẹ̀ kò yi kuro, ṣugbọn
ọwọ́ rẹ̀ nà jade sibẹ.
5 Egbe ni fun Assuri, ọgọ ibinu mi, ati
ọ̀pa ọwọ́ wọn ni irúnu mi.
6 Emi o ran a si orilẹ-ède agabàgebe, ati
fun awọn enia ibinu mi li emi o paṣẹ kan,
lati ko ikogun, ati lati mu ohun ọdẹ, ati
lati tẹ̀ wọn mọlẹ bi ẹrẹ̀ ni igboro.
7 Ṣugbọn on kò rò bẹ̃, bẽni ọkàn rẹ̀ kò

Digitized by Google

rò bẹ̃ ; ṣugbọn o wà li ọkàn rẹ̀ lati parun
ati lati ke orilẹ-ède kuro, ki iṣe diẹ.
8 Nitori o wipe, Ọba kọ awọn ọmọ-alade
mi ha jẹ patapata ?
9 Kalno kò ha dabi Karkemiṣi ? Hama-
ti kò ha dabi Arpadi ? Samaria kò ha dabi
Damasku ?
10 Gẹgẹ bi ọwọ́ mi ti nà de ijọba ere ri,
ere eyi ti o jù ti Jerusalemu ati ti Samaria
lọ.
11 Bi emi ti ṣe si Samaria ati ere rẹ̀, emi
kì yio ha ṣe bẹ̃ si Jerusalemu ati ere rẹ̀ bi ?
12 Nitorina yio si ṣe, nigbati Oluwa ti
ṣe gbogbo iṣẹ rẹ̀ lori òke Sioni ati Jerusale-
mu, emi o ba eso aiya lile ọba Assiria wi,
ati ogo ìwo giga rẹ̀.
13 Nitori o wipe, nipa agbara ọwọ́ mi ni
emi ti ṣe e, ati nipa ọgbọ́n mi ; nitori emi
moye, emi si ti mu àla awọn enia kuro,
emi si ti ji iṣura wọn, emi si ti sọ awọn
aralu na kalẹ bi alagbara ọkọnrin.
14 Ọwọ́ mi si ti wá ọrọ̀ awọn enia ri bi
itẹ ẹiyẹ : ati gẹgẹ bi ẹnipe ẹnikan nko ẹyin
ti o kù, li emi ti kó gbogbo aiye jọ ; kò si
ẹniti o gbọ̀n iyẹ, tabi ti o ya ẹnu, tabi ti o
dún.
15 Ãke ha le fọnnu si ẹniti nfi i la igi ?
tabi ayùn ha le gbe ara rẹ̀ ga si ẹniti nmì i ?
bi ẹnipe ọgọ le mì ara rẹ̀ si awọn ti o gbe e
soke, tabi bi ẹnipe ọpa le gbe ara rẹ̀ soke,
bi ẹnipe ki iṣe igi.
16 Nitorina ni Oluwa, Oluwa awọn
ọmọ-ọgun yio mu awọn tirẹ̀ ti o sanra di
rirù : ati labẹ ogo rẹ̀ yio da jijo kan bi jijo
iná.
17 Imọlẹ Israeli yio si jẹ iná, ati Ẹni-
Mimọ́ rẹ̀ yio jẹ ọwọ́-iná : yio si jo ẹgún ati
ẹwọn rẹ̀ run, li ọjọ kan ;
18 Yio si jo ogo igbó rẹ̀ run, ati oko rẹ̀
ẹlẹtù loju, ati ọkàn ati ara : nwọn o si dabi
igbati ọlọpagun ndakú.
19 Iyokù igi igbó rẹ̀ yio si jẹ diẹ, ti
ọmọde yio le kọwe wọn.
20 Yio si ṣe li ọjọ na, iyokù Israeli, ati
iru awọn ti o salà ni ile Jakobu, ki yio tun
duro tì ẹniti o lù wọn mọ ; ṣugbọn nwọn o
duro tì Oluwa, Ẹni-Mimọ Israeli, li otitọ.
21 Awọn iyokù yio pada, awọn iyokù ti
Jakobu, si Ọlọrun alagbara.
22 Bi Israeli enia rẹ ba dàbi iyanrìn
okun, sibẹ iyokù ninu wọn o pada : aṣẹ
iparun na yio kun akunwọ́-silẹ ninu ododo.
23 Nitori Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-ogun
yio ṣe iparun, ani ipinnu, li ãrin ilẹ gbogbo.
24 Nitorina bayi li Oluwa, Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi, Ẹnyin enia mi ti ngbe Sioni,
ẹ má bẹ̀ru awọn ara Assiria : on o fi ọgọ lù
ọ, yio si gbe ọpa rẹ̀ soke si ọ, gẹgẹ bi iru ti
Egipti.
25 Ṣugbọn niwọn igba diẹ kiun, irunú
yio si tan, ati ibinu mi ninu iparun wọn.
26 Oluwa awọn ọmọ-ogun yio gbe paṣan
kan soke fun u, gẹgẹ bi ipakupa ti Midiani
ni apata Orebu : ati gẹgẹ bi ọgọ rẹ̀ soju
okun, bẹ̃ni yio gbe e soke gẹgẹ bi iru ti
Egipti.
27 Yio si ṣe li ọjọ na, ni a o gbe ẹrù rẹ̀
kuro li ejika rẹ, ati àjaga rẹ̀ kuro li ọrùn
rẹ, a o si ba àjaga na jẹ nitori ọra pupọ̀.
28 On de si Aiati, on ti kọja si Migroni ;
ni Mikmaṣi li on ko ẹrù-ogun rẹ̀ jọ si :
29 Nwọn ti rekọja ọ̀na na : nwọn ti wọ̀
ni Geba ; Rama bẹ̀ru ; Gibea ti Saulu sá.
30 Gbe ohùn rẹ soke, ọmọbirin Gallimu :
mu ki a gbọ́ ọ de Laiṣi, otòṣi Anatoti.
31 A ṣi Madmena nipo dà ; awọn ara
Gebimu ko ara wọn jọ lati sa.
32 Yio duro sibẹ ni Nobu li ọjọ na : on
o si mì ọwọ́ rẹ̀ si oke giga ọmọbirin Sioni,
oke kekere Jerusalemu.
33 Kiyesi i, Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-
ọgun yio fi ẹ̀ru wọ́n ẹka : ati awọn ti o ga
ni inà li a o ke kuro, ati awọn agberaga li
a o rẹ̀ silẹ.
34 On o si fi irin ke pantiri igbó lu ilẹ,
Lebanoni yio si ṣubu nipa alagbara kan.

## ORI 11.

ẸKÀN kan yio si jade lati inu kùkute
Jesse wá, ẹka kan yio si hù jade lati
inu gbòngbo rẹ̀ :
2 Ẹmi Oluwa yio si bà le e, ẹmi ọgbọ́n
ati oye, ẹmi igbimọ̀ ati agbara, ẹmi imọ̀ran
ati ibẹ̀ru Oluwa.
3 Õrùn-didùn rẹ̀ si wà ni ibẹ̀ru Oluwa,
on ki yio si dajọ nipa ìri oju rẹ̀, bẹ̃ni ki yio
dajọ nipa gbigbọ́ eti rẹ̀ ;
4 Ṣugbọn yio fi ododo ṣe idajọ talakà,
yio si fi otitọ ṣe idajọ fun awọn ọlọkàn tùtu
aiye ; on o si fi ọgọ ẹnu rẹ̀ lu aiye, on o si
fi ẽmi ète rẹ̀ lu awọn enia buburu pa.
5 Ododo yio si jẹ amure ẹgbẹ́ rẹ̀, ati iṣo-
titọ amure inu rẹ̀.
6 Ikõkò pẹlu yio ma ba ọdọ-agutan gbe
pọ̀, kiniun yio si dubulẹ pẹlu ọmọ ewurẹ ;
ati ọmọ malũ ati ọmọ kiniun ati ẹgbọ̀rọ
ẹran abọpa yio ma gbe pọ̀ ; ọmọ kekere yio
si ma dà wọn.
7 Malũ ati beari yio si ma jẹ pọ̀ ; ọmọ
wọn yio dubulẹ pọ̀ ; kiniun yio si jẹ koriko
bi malũ.

Digitized by Google

8 Ọmọ ẹnu-ọmu yio si ṣire ni ihò pã-
mọlẹ, ati ọmọ ti a já lẹnu-ọmu yio si fi ọwọ́
rẹ̀ si ihò gunte.
9 Nwọn ki yio panilara, bẽni nwọn ki
yio panirun ni gbogbo oke mimọ́ mi:
nitori aiye yio kún fun ìmọ Oluwa gẹgẹ bi
omi ti bò okun.
10 Ati li ọjọ na kùkute Jesse kan yio
wà, ti yio duro fun ọpágun awọn enia; on
li awọn keferi yio wá ri: isimi rẹ̀ yio si li
ogo.
11 Yio si ṣe li ọjọ na, ni Oluwa yio tun
nawọ rẹ̀ lati gbà awọn enia rẹ̀ iyokù padà,
ti yio kù, lati Assiria, ati lati Egipti, ati
lati Patrosi, ati lati Kuṣi, ati lati Elamu,
ati Ṣinari, ati lati Hamati, ati lati awọn
erekùṣu okun wá.
12 On o si gbe ọpagun kan duro fun
awọn orilẹ-ède, yio si gbá awọn aṣati Israeli
jọ, yio si kó awọn ti a tuka ni Juda jọ latí
igun mẹrin aiye wá.
13 Ilara Efraimu yio si tan kuro;
Efraimu ki yio ṣe ilara Juda, Juda ki yio
si bà Efraimu ninu jẹ.
14 Ṣugbọn nwọn o si fò mọ ejika awọn
Filistini siha iwọ̀-õrùn; nwọn o jùmọ bà
awọn ti ilà-õrùn jẹ: nwọn o si gbe ọwọ́
le Edomu ati Moabu; awọn ọmọ Ammoni
yio si gbà wọn gbọ́.
15 Oluwa yio si pa ahọn okun Egipti
run tũtũ; ẹfũfu lile rẹ̀ ni yio si mì ọwọ́ rẹ̀
lori odo na, yio si lù u ni iṣàn meje, yio si
jẹ ki enia rekọja ni batà gbigbẹ.
16 Ọna opopo kan yio si wà fun iyokù
awọn enia rẹ̀, ti yio kù, lati Assiria; gẹgẹ
bi o ti ri fun Israeli li ọjọ ti o goke jade
kuro ni ilẹ Egipti.

## ORI 12.

ATI li ọjọ na iwọ o si wipe, Oluwa, emi o
yìn ọ́: bi o tilẹ ti binu si mi, ibinu
rẹ ti yi kuro, iwọ si tù mi ninu.
2 Kiyesi i, Ọlọrun ni igbala mi; emi o
gbẹkẹle, emi ki yio si bẹ̀ru: nitori Oluwa
Jehofah li agbara mi ati orin mi; on pẹlu
si di igbala mi.
3 Ẹnyin o si fi ayọ̀ fà omi jade lati inu
kanga igbala wá.
4 Li ọjọ na li ẹnyin o si wipe, Yìn Olu-
wa, kepe orukọ rẹ̀, sọ iṣe rẹ̀ lãrin awọn
enia, mu u wá si iranti pe, orukọ rẹ̀ li a
gbe leke.
5 Kọrin si Oluwa: nitori o ti ṣe ohun
didara: eyi di mimọ̀ ni gbogbo aiye.
6 Kigbe, si hó, iwọ olugbe Sioni: nitori
ẹni titobi ni Ẹni-Mimọ Israeli li ãrin rẹ.

## ORI 13.

ỌRỌ-ÌMỌ niti Babiloni ti Isaiah ọmọ
Amosi ri.
2 Ẹ gbe ọpágun soke lori oke giga, ẹ kọ
si wọn, ẹ juwọ, ki nwọn ba le lọ sinu ẹnu-
odi awọn ọlọla.
3 Emi ti paṣẹ fun awọn temi ti a yà si
mimọ́, emi ti pe awọn alagbara mi pẹlu fun
ibinu mi, ani awọn ti nwọn yọ̀ ninu ọlanla
mi.
4 Ariwo ọ̀pọlọpọ lori oke, gẹgẹ bi ti enia
pupọ̀: ariwo rudurudu ti ijọba awọn orilẹ-
ède, ti a kojọ pọ̀: Oluwa awọn ọmọ-ogun
gbá ogun awọn ọmọ-ogun jọ.
5 Nwọn ti ilẹ okerè wá, lati ipẹkun
ọrun, ani, Oluwa, ati ohun-elò ibinu rẹ̀,
lati pa gbogbo ilẹ run.
6 Ẹ hu; nitori ọjọ Oluwa kù si dẹdẹ;
yio de bi iparun lati ọdọ Olodumare wá.
7 Nitorina gbogbo ọwọ́ yio rọ, ọkàn
olukuluku enia yio si di yiyọ́.
8 Nwọn o si bẹ̀ru: irora ati ikãnu yio dì
wọn mu; nwọn o wà ni irora bi obirin ti
nrọbi: ẹnu yio yà ẹnikan si ẹnikeji rẹ̀;
oju wọn yio dabi ọwọ́-iná.
9 Kiyesi i, ọjọ Oluwa mbọ̀ wá, o ni ibi
ton ti ikọnnu ati ibinu gbigboná, lati sọ
ilẹ na di ahoro: yio si pa awọn ẹlẹṣẹ run
kuro ninu rẹ̀.
10 Nitori awọn iràwọ ọrun, ati iṣùpọ-
iràwọ inu rẹ̀ kì yio tàn imọlẹ wọn: õrùn
yio ṣu okùnkun ni ijadelọ rẹ̀, oṣùpa kì yio
si mu ki imọlẹ rẹ̀ tàn.
11 Emi o si bẹ̀ ibi wò lara aiye, ati aiṣe-
dẽde lara awọn enia buburu; emi o si mu
ki igberaga awọn agberaga ki o mọ, emi o
si mu igberaga awọn alagbara rẹ̀ silẹ.
12 Emi o mu ki ọkọnrin kan ṣọwọ́n ju
wura lọ; ani enia kan ju wura Ofiri dara-
dara.
13 Nitorina emi o mu ọrun mì-titi, ilẹ
aiye yio si ṣipò rẹ̀ pada, ninu ibinu Oluwa
awọn ọmọ-ogun, ati li ọjọ ibinu gbigbona
rẹ̀.
14 Yio si dabi abo agbọ̀nrin ti a nlepa,
ati bi agutan ti ẹnikan kò gbajọ: olukulu-
ku wọn o yipada si enia rẹ̀, olukuluku yio
si sa si ilẹ rẹ̀.
15 Ẹnikẹni ti a ri li a o gun li agunyọ;
ẹnikẹni ti o si dà ara rẹ̀ pọ̀ mọ́ wọn yio ti
ipa idà ṣubu.
16 Ọmọ wọn pẹlu li a o fọ́ tũtu loju ara
wọn; a o si kó wọn ni ile, a o si fi agbara
bà obirin wọn jẹ́;
17 Kiyesi i, emi o gbe awọn ara Media

Digitized by Google

dide si wọn, ti ki yio ka fadakà si; bi o si
ṣe ti wura, nwọn ki yio ni inu didùn si i.
18 Ọrun wọn pẹlu yio fọ́ awọn ọdọmọ-
kọnrin tũtũ; nwọn ki yio ṣãnu fun ọmọ-
inu: oju wọn kì yio dà ọmọde si.
19 Ati Babiloni, ogo ijọba gbogbo, ẹwà
ogo Kaldea, yio dabi igbati Ọlọrun bi So-
domu on Gomorra ṣubu.
20 A kì yio tẹ̀ ẹ dó mọ, bẽni o kì yio si
gbe ibẹ̀ mọ lati irandiran: bẽni awọn ara
Arabia kì yio pagọ nibẹ mọ; bẽni awọn
oluṣọ-agutan kì yio kọ́ agbo wọn nibẹ mọ.
21 Ṣugbọn ẹranko igbẹ yio dubulẹ nibẹ;
ile wọn yio si kun fun òwiwí, abo ogòngo
yio ma gbe ibẹ, ọ̀rọ̀ yio si ma jo nibẹ.
22 Awọn ọ̀wawa yio si ma ke ninu ãfin
wọn, ati dragoni ninu gbangàn wọn dara-
dara: ìgba rẹ̀ si sunmọ etile, a kì yio si fa
ọjọ rẹ̀ gùn.

## ORI 14.

NITORI Oluwa yio ṣãnu fun Jakobu, yio
si tun yan Israeli, yio si mu wọn gbe
ilẹ wọn; alejò yio si dapọ̀ mọ wọn, nwọn o
si faramọ ile Jakobu.
2 Awọn enia yio si mu wọn, nwọn o si
mu wọn wá si ipò wọn: ile Israeli yio si
ni wọn ni ilẹ Oluwa, fun iranṣẹ-kọnrin ati
iranṣẹ-birin: awọn ti o ti kó wọn ni igbe-
kun ni nwọn o kó ni igbekun; nwọn o si
ṣe akoso aninilara wọn.
3. Yio si ṣe li ọjọ ti Oluwa yio fun ọ ni
isimi kuro ninu ibanujẹ rẹ, ati kuro ninu
ijaiya rẹ, ati kuro ninu oko-ẹru lile nibiti
a ti mu ọ sìn,
4 Ni iwọ o si fi ọba Babiloni ṣẹ̀fẹ yi, ti
iwọ o si wipe, Aninilara nì ha ti ṣe dakẹ!
alọnilọwọgbà wura dakẹ!
5 Oluwa ti ṣẹ ọpá oluṣe-buburu, ati ọpá-
alade awọn alakoso.
6 Ẹniti o fi ibinu lù awọn enia lai dawọ
ro, ẹniti o fi ibinu ṣe akoso awọn orilẹ-ède,
li a nṣe inunibini si, lai dẹkun.
7 Gbogbo aiye simi, nwọn si gbe jẹ:
nwọn bú jade ninu orin kikọ.
8 Nitõtọ, igi firi nyọ̀ ọ, ati igi kedari ti
Lebanoni, wipe, Lati ìgba ti iwọ ti dubulẹ,
kò si akegi ti o tọ̀ wa wá.
9 Ipò-okú lati isalẹ wá mì fun ọ lati
pade rẹ li àbọ rẹ: o rú awọn okú dide fun
ọ, ani gbogbo awọn alakoso aiye; o ti gbe
gbogbo ọba awọn orilẹ-ède dide kuro lori
itẹ wọn.
10 Gbogbo wọn o dahùn, nwọn o si wi
fun ọ pe, Iwọ pẹlu ti di ailera gẹgẹ bi awa?
iwọ ha dabi awa?
11 Ogo rẹ li ati sọ̀kalẹ si ipò-okú, ati
ariwo durù rẹ: ekòlo ti tàn sabẹ rẹ, idin si
bò ọ mọ ilẹ.
12 Bawo ni iwọ ti ṣe ṣubu lati ọrun wá,
Iwọ Lusiferi, iràwọ owurọ! bawo li a ti ṣe
ke ọ lu ilẹ, iwọ ti o ti ṣẹ́ awọn orilẹ-ède li
apá!
13 Nitori iwọ ti wi li ọkàn rẹ pe, Emi o
goke lọ si ọrun, emi o gbe itẹ mi ga kọja
iràwọ Ọlọrun: emi o si joko lori oke ijọ
enia ni iha ariwa:
14 Emi o goke kọja giga awọsanma:
emi o dabi ọga-ogo jùlọ.
15 Ṣugbọn a o mu ọ sọkalẹ si ipò okú,
si iha ihò.
16 Awọn ti o ri ọ yio tẹjumọ ọ, nwọn o
si ronu rẹ pe, Eyi li ọkọnrin na ti o mu
aiye warìri, ti o mu ilẹ ọba mìtiti;
17 Ti o sọ aiye dàbi aginju, ti o si pa ilu
rẹ̀ run; ti kò dá awọn ondè rẹ̀ silẹ lati lọ
ile?
18 Gbogbo ọba awọn orilẹ-ède, ani gbo-
gbo wọn, dubulẹ ninu ogo, olukuluku ninu
ile rẹ̀.
19 Ṣugbọn iwọ li a gbe sọnù kuro nibi
iboji rẹ bi ẹka irira, bi aṣọ awọn ti a pa,
awọn ti a fi idà gun li agunyọ, ti nsọkalẹ
lọ si ihò okuta; bi okú ti a tẹ̀ mọlẹ.
20 A kì o sin ọ pọ̀ pẹlu wọn, nitoriti
iwọ ti pa ilẹ rẹ run, o si ti pa awọn enia
rẹ: iru awọn oluṣe buburu li a kì o darukọ
lailai.
21 Mura ibi pipa fun awọn ọmọ rẹ̀, ni-
tori aiṣedẽde awọn baba wọn; ki nwọn ki
o má ba dide, ki nwọn ni ilẹ na, ki nwọn
má si fi ilu-nla kun oju aiye.
22 Nitori emi o dide si wọn, li Oluwa
awọn ọmọ-ogun wi; emi o si ke orukọ ati
iyokù kuro ni Babiloni, ati ọmọ, ati ọmọ
de ọmọ, ni Oluwa wi.
23 Emi o si ṣe e ni ilẹnini fun õrẹ̀, ati
àbata omi; emi o si fi ọwọ̀ iparun gbá a, li
Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
24 Oluwa awọn ọmọ-ogun ti bura, wipe,
Lõtọ gẹgẹ bi mo ti gberò, bẽni yio ri, ati
gẹgẹ bi mo ti pinnu, bẽni yio si duro:
25 Pe, emi o fọ́ awọn ara Assiria ni ilẹ
mi, ati lori oke mi li emi o tẹ̀ ọ mọlẹ
labẹ ẹsẹ: nigbana li ajàga rẹ̀ yio kuro lara
wọn, ati ẹrù rẹ̀ kuro li ejika wọn.
26 Eyi ni ipinnu ti a pinnu lori gbogbo
aiye: eyi si ni ọwọ́ ti a nà jade lori gbogbo
orilẹ-ède.
27 Nitori Oluwa awọn ọmọ-ogun ti pin-
nu, tani yio si sọ ọ di asan? ọwọ́ rẹ̀ si nà
jade, tani yio si dá a padà?

Digitized by Google

28 Li ọdun ti Ahasi ọba kú, li ọ̀rọ-imọ
yi wà.
29 Iwọ máṣe yọ̀, gbogbo Filistia, nitori
paṣan ẹniti o nà ọ ṣẹ́; nitori lati inu gbòn-
gbo ejo ni pãmọlẹ kan yio jadewá, irú rẹ̀
yio si jẹ́ ejò iná ti nfò.
30 Akọbi awọn otòṣi yio si jẹ, awọn
alaini yio si dubulẹ lailewu; emi o si fi
iyàn pa gbòngbo rẹ, on o si pa iyokù rẹ.
31 Hu, iwọ ẹnu-odi; kigbe, iwọ ilu;
gbogbo Palestina, iwọ ti di yiyọ́: nitori
ẽfin yio ti ariwa jade wá, ẹnikan kì yio si
yà ara rẹ̀ kuro lọdọ ẹgbẹ́ rẹ̀.
32 Esi wo li a o fi fun awọn ikọ̀ orilẹ-
ède? Pe, Oluwa ti tẹ̀ Sioni dó, talaka ni-
nu awọn enia rẹ̀ yio si sá wọ̀ inu rẹ̀.

## ORI 15.

ỌRỌ-ÌMỌ niti MOABU. Nitori li oru li
a sọ Ari ti Moabu di ahoro, a si mu u
dakẹ; nitori li oru li a sọ Kiri ti Moabu di
ahoro, a si mu u dakẹ;
2 On ti goke lọ si Bajiti, ati si Diboni,
ibi giga wọnni, lati sọkun: Moabu yio hu
lori Nebo, ati lori Medeba: gbogbo ori wọn
ni yio pá, irungbọn olukuluku li a o fá.
3 Ni igboro ni nwọn o da aṣọ-ọ̀fọ bò ara
wọn: lori oté ile wọn, ati ni igboro wọn,
olukuluku yio hu, yio si ma sọkun pẹ̀rẹpẹ̀rẹ.
4 Heṣboni yio si kigbe, ati Eleale: a o
si gbọ́ ohùn wọn titi de Jahasi: nitorina
ni awọn ọmọ-ogun Moabu ti o hamọra yio
kigbe soke; ọkàn rẹ̀ yio bajẹ fun ara rẹ̀.
5 Ọkàn mi kigbe soke fun Moabu; awọn
isánsa rẹ̀ sá de Soari, abo-malũ ọlọdun
mẹta: ni gigun oke Luhiti tẹkúntẹkún ni
nwọn o ma fi gùn u lọ; niti ọna Horonai-
mu nwọn o gbe ohùn iparun soke.
6 Nitori awọn omi Nimrimu yio di aho-
ro: nitori koriko nrọgbẹ, eweko nkú lọ,
ohun tutù kan kò si.
7 Nitorina ọ̀pọ eyi ti nwọn ti ni, ati eyi
ti nwọn ti kojọ, ni nwọn o gbe kọja odò
willo.
8 Nitori igbe na ti yi agbegbè Moabu
ka; igbe na si de Eglaimu, ati igbe na de
Beerelimu.
9 Nitori odò Dimoni yio kún fun ẹ̀jẹ:
nitori emi o fi ibi miran sori Dimoni, emi
o mu kiniun wá sori ẹniti o salà kuro ni
Moabu, ati lori awọn ti o kù ni ilẹ na.

## ORI 16.

ERÁN ọdọ-agutan si alakoso ilẹ lati
Sela wá si aginju, si oke ọmọbirin
Sioni.
2 Yio si ṣe, bi alarinkiri ẹiyẹ ti a le jade
kuro ninu itẹ́-ẹiyẹ, bẹ̃ni ọmọbirin Moabu
yio ri ni iwọdò Arnoni.
3 Ẹ gbìmọ, ẹ mu idajọ ṣẹ; ṣe ojiji rẹ bi
oru li ãrin ọsángangan; pa awọn ti a le
jade mọ́; máṣe fi isánsa hàn.
4 Moabu, jẹ ki awọn isánsa mi ba ọ gbe,
iwọ ma jẹ ãbo fun wọn li oju akoni: nitori
alọnilọwọgbà de opin, akoni dasẹ̀, a pa
awọn aninilara run kuro lori ilẹ.
5 Ninu ãnu li a o si fi idi ilẹ mulẹ: yio
si joko lori rẹ̀ li otitọ ninu agọ Dafidi, yio
ma ṣe idajọ, yio si ma wá idajọ, yio si ma
mu ododo yara kánkán.
6 Awa ti gbọ́ ti igberaga Moabu; o
gberaga pọju: ani ti irera rẹ̀, ati igberaga
rẹ̀, ati ibinu rẹ̀; ihalẹ rẹ̀ asan ni.
7 Nitorina ni Moabu yio hu fun Moabu,
gbogbo wọn o hu; nitori ipilẹ Kir-hareseti
li ẹnyin o gbàwẹ; nitõtọ a lù wọn.
8 Nitori igbẹ́ Heṣboni rọ, ati àjara
Sibma: awọn oluwa awọn keferi ti ke pa-
takì ọ̀gbin rẹ̀ lu ilẹ, nwọn tàn de Jaseri,
nwọn nrìn kakiri aginjù: ẹka rẹ̀ nà jade,
nwọn kọja okun.
9 Nitorina emi o pohùnrére ẹkun, bi
ẹkun Jaseri, àjara Sibma: emi o fi omije
mi rin ọ, iwọ Heṣboni, ati Eleale: nitori
ariwo nla ta lori eso-igi ẽrùn rẹ, ati lori
ikore rẹ.
10 A si mu inu-didun kuro, ati ayọ̀
kuro ninu oko ti nso eso ọ̀pọlọpọ; orin kì
yio si si mọ ninu ọgbà-àjara, bẹ̃ni kì yio si
ihó-ayọ̀ mọ: afọnti kì yio fọn ọti-waini
mọ ninu ifọnti wọn, emi ti mu ariwo dá.
11 Nitorina inu mi yio dún bi harpu fun
Moabu, ati ọkàn mi fun Kir-haresi.
12 Yio si ṣe, nigbati a ba ri pe ãrẹ̀ mu
Moabu ni ibi giga, ni yio wá si ibi-mimọ́
rẹ̀ lati gbadura; ṣugbọn kì yio bori.
13 Eyi li ọ̀rọ ti Oluwa ti sọ niti Moabu
lati igbà na wá.
14 Ṣugbọn nisisiyi Oluwa ti sọ̀rọ, wipe,
Niwọn ọdun mẹta, gẹgẹ bi ọdun alagbaṣe,
a o si kẹgàn ogo Moabu, pẹlu gbogbo ọ̀pọ-
lọpọ nì: awọn iyokù yio kere, kì yio si li
agbara.

## ORI 17.

ỌRỌ-ÌMỌ niti Damasku. Kiye si i, a mu
Damasku kuro lati ma jẹ ilu, yi o si
di òkiti àlapa.
2 A kọ̀ gbogbo ilu Aroeri silẹ: nwọn o
jẹ ti ọ̀wọ-ẹran, ti yio dubulẹ, ẹnikẹni kì
yio dẹrubà wọn.
3 Odi kì yio si si mọ ni Efraimu, ati

Digitized by Google

ijọba ni Damasku, ati iyokù ti Siria: nwọn
o dabi ogo awọn ọmọ Israeli, li Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi.
4 Li ọjọ na yio si ṣe, a o mu ogo Jakobu
dinkù, ati sisanra ara rẹ̀ li a o sọ di rirù.
5 Yio si dabi igbati alakorè nkó agba-
do jọ, ti o si nfi apá rẹ̀ ré ipẹ́-ọkà: yio si
dabi ẹniti nkó ipẹ́-ọkà jọ ni afonifoji
Refaimu.
6 Ṣugbọn ẽṣẹ́ eso-àjara yio hù ninu rẹ̀,
gẹgẹ bi mimì igi olifi, eso kekere meji bi
mẹta ni ṣonṣo oke ẹka, mẹrin bi marun ni
ẹka ode ti o ni eso pupọ, li Oluwa Ọlọrun
Israeli wi.
7 Li ọjọ na li ẹnikan yio wò Ẹlẹda rẹ̀,
ati oju rẹ yio si bọ̀wọ fun Ẹni-Mimọ
Israeli.
8 On kì yio si wò pẹpẹ, iṣẹ ọwọ́ rẹ̀, bẽni
kì yio si bọ̀wọ fun eyi ti ika rẹ̀ ti ṣe, yala
igbo-òriṣa tabi ere-õrun.
9 Li ọjọ na ni ilu alagbara rẹ̀ yio dabi
ẹka ìkọsilẹ, ati ẹka tente oke ti nwọn fi
silẹ nitori awọn ọmọ Israeli: iparun yio si
wà.
10 Nitori iwọ ti gbagbe Ọlọrun igbala
rẹ, ti iwọ kò si nani apata agbara rẹ, nito-
rina ni iwọ ti gbìn ọ̀gbin daradara, iwọ si
tọ́ àjeji ẹka sinu rẹ̀.
11 Li ọjọ na ni iwọ o mu ki ọ̀gbin rẹ
dàgba, ati li owurọ ni iwọ o mu ki irugbin
rẹ rú: ṣugbọn a o mu ikorè lọ li ọjọ ini,
ikãnu kikoro yio si wà.
12 Egbé ni fun ariwo ọ̀pọ enia, ti o pa
ariwo bi ariwo okun; ati fun iró awọn
orilẹ-ède, ti nwọn rọ bi riró omi pupọ̀!
13 Awọn orilẹ-ède yio ró bi riró omi
pupọ: ṣugbọn Ọlọrun yio bá wọn wi, nwọn
si sa jina rere, a o si lepa wọn gẹgẹ bi ìyan-
gbo oke-nla niwaju ẹfũfu, ati gẹgẹ bi ohun
yiyi niwaju ãjà.
14 Si kiye si i, li aṣalẹ, iyọnu; ki ilẹ to
mọ́ on kò si. Eyi ni ipín awọn ti o kó wa,
ati ipín awọn ti o jà wa li olè.

## ORI 18.

EGBE ni fun ilẹ ti o ni ojiji apá mẹji, ti
o wà ni ikọja odò Etiopia:
2 Ti o rán awọn ikọ̀ li ọ̀na okun, ani
ninu ọkọ̀ koriko odò, li oju odò, wipe, Lọ,
ẹnyin onṣẹ ti o yara kánkan, si orilẹ-ède ti
a nà ká ti a si tẹju, si enia ti o ni ibẹ̀ru
lati igbayi ati titi lọ; orilẹ-ède ti o ni
ipá, ti o si tẹ̀ ni mọlẹ, ilẹ ẹniti odò pupọ̀
pinyà!
3 Gbogbo ẹnyin ti ngbe aiye, ati olugbé
aiye, ẹ wò, nigbati on gbe ọpagun sori
awọn oke giga; ati nigbati on fọn ipè, ẹ
gbọ́.
4 Nitori bẽli Oluwa sọ fun mi, emi o
simi, emi o si gbèro ninu ibugbé mi, bi
oru ọsángangan, ati bi awọsanma ìri, ninu
oru ikorè.
5 Nitori ṣaju ikorè, nigbati ìrudi ba kún,
ti itanná ba di eso-àjara pipọn, on o fi dojé
ré ẹka-titun, yio si mu kuro, yio si ke ẹka
lu ilẹ.
6 A o si fi wọn silẹ fun awọn ẹiyẹ oke-
nla, ati fun awọn ẹranko aiye: awọn ẹiyẹ
yio yá õrùn lori wọn, gbogbo awọn ẹranko
aiye yio si potutù lori wọn.
7 Li akoko na ni a o mu ọrẹ wá fun
Oluwa awọn ọmọ-ogun lati ọdọ awọn enia
ti a nà ka, ti a si tẹju, ati enia ti o ni ibẹ̀ru
lati igbayi ati titi lọ; orilẹ-ède ti o ni ipá
ti o tẹ̀ ni mọlẹ, ilẹ ẹniti odò pupọ̀ pinyà, si
ibi orukọ Oluwa awọn ọmọ-ogun, oke giga
Sioni.

## ORI 19.

ỌRỌ-ÌMỌ niti Egipti. Kiyesi i, Oluwa
ngùn awọsanma ti o yara, yio si wá
si Egipti: a o si ṣi ipò awọn òriṣa Egipti
pàda niwaju rẹ̀, aiya Egipti yio yọ́ li ãrin
rẹ̀.
2 Emi o si gbe Egipti dide si Egipti:
olukuluku yio si ba arakọnrin rẹ̀ jà, ati
olukuluku aladugbò rẹ̀; ilu yio dojukọ ilu,
ati ijọba yio dojùkọ ijọba.
3 Ẹmi Egipti yio si rẹ̀wẹsi lãrin inu rẹ̀;
emi o si pa ìmọ inu rẹ run: nwọn o si wá
a tọ̀ òriṣa lọ, ati sọdọ awọn atuju, ati sọdọ
awọn ajẹ́, ati sọdọ awọn oṣó;
4 Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-ogun wipe,
awọn ara Egipti li emi o fi le oluwa on-
rorò li ọwọ́; ọba ti o muna yio ṣe akoso
wọn.
5 Omi yio si buṣe li okun, a o si fi odò
ṣofo, yio si gbẹ.
6 Odò yio si di rirùn; odò ãbo li a o sọ
di ofo, ti a o si gbọ́n gbẹ; oko-odò ati iyè
yio rọ.
7 Oko-tutù ni ipadò, li ẹnu odò, ati
ohun gbogbo ti a gbìn sipadò, ni yio rọ,
yio funka, kì yio si si mọ.
8 Awọn apẹja yio gbàwẹ pẹlu, ati gbo-
gbo awọn ti nfì ìwọ li odò yio pohùnrére-
ẹkun; ati awọn ti nda àwọn li odò yio
sorikọ́.
9 Pẹlupẹlu awọn ti nṣiṣẹ ọ̀gbọ daradara,
ati awọn ti nwun aṣọ-àla yio dãmu.
10 A o si fọ́ wọn ni ipilẹ rẹ̀, gbogbo awọn
alagbàṣe li a o bà ni inu jẹ.



Digitized by Google

11 Nitõtọ òpe ni awọn ọmọ-alade Soani, ìmọ awọn ìgbimọ ọlọgbọn Farao di wère: ẹ ha ti ṣe sọ fun Farao, pe, Emi li ọmọ ọlọgbọn, ọmọ awọn ọba igbãni?

12 Awọn dà? awọn ọlọgbọn rẹ dà? si jẹ ki nwọn sọ fun ọ nisisiyi, si jẹ ki nwọn mọ̀ ete ti Oluwa awọn ọmọ-ogun ti pa le Egipti.

13 Awọn ọmọ-alade Soani di aṣiwère, a tàn awọn ọmọ-alade Nofi jẹ; ani awọn ti iṣe pataki ẹyà rẹ̀.

14 Oluwa ti mí ẽmi iyapa si inu rẹ̀ na: nwọn si ti mu Egipti ṣina ninu gbogbo iṣẹ inu rẹ̀, gẹgẹ bi ọ̀muti enia ti nta gbọngbọ́n ninu ẽbi rẹ̀.

15 Bẽni kì yio si iṣẹkiṣẹ fun Egipti, ti ori tabi ìru, ẹka tabi oko-odò, le ṣe.

16 Li ọjọ na ni Egipti yio dabi obirin; yio si wariri, ẹ̀ru yio si bà a nitori mimì ọwọ́ Oluwa awọn ọmọ-ogun ti o mì le e lori.

17 Ilẹ Juda yio si di ẹ̀ru fun Egipti, olukuluku ẹniti o dá a sọ ninu rẹ̀ yio tikararẹ̀ bẹ̀ru, nitori ìmọ Oluwa awọn ọmọ-ogun, ti o ti gbà si i.

18 Li ọjọ na ni ilu marun ni ilẹ Egipti yio fọ̀ ède Kenaani, ti nwọn o sì bura si Oluwa awọn ọmọ-ogun; a o ma pè ọkan ni, Ilu ìparun.

19 Li ọjọ na ni pẹpẹ kan yio wà fun Oluwa li ãrin ilẹ Egipti, ati ọwọ̀n ni àgbegbe inu rẹ̀ fun Oluwa.

20 Yio si jẹ fun ami, ati fun ẹ̀ri si Oluwa awọn ọmọ-ogun ni ilẹ Egipti: nitori nwọn o kigbe pè Oluwa nitori awọn aninilara, yio si rán olugbala kan si i, ati ẹni-nla, on o si gbà wọn.

21 Oluwa yio si di mimọ̀ fun Egipti, awọn ara Egipti yio si mọ̀ Oluwa li ọjọ na, nwọn o si rú ẹbọ, nwọn o si ta ọrẹ; nitõtọ nwọn o jẹ'jẹ fun Oluwa, nwọn o si mu u ṣẹ.

22 Oluwa o si lù Egipti bolẹ, yio si mu u li ara da: nwọn o si yipada si Oluwa, on o si gbọ́ ẹ̀bẹ wọn, yio si mu wọn li ara da.

23 Li ọjọ na ni opopo kan yio wà lati Egipti de Assiria, awọn ara Assiria yio si wá si Egipti, awọn ara Egipti si Assiria, awọn ara Egipti yio si sìn pẹlu awọn ara Assiria.

24 Li ọjọ na ni Israeli yio jẹ ẹkẹta pẹlu Egipti ati pẹlu Assiria, ani ibukún li ãrin ilẹ na:

25 Ti Oluwa awọn ọmọ-ogun yio bukún fun, wipe, Ibukun ni fun Egipti enia mi, ati fun Assiria iṣẹ ọwọ́ mi, ati fun Israeli ini mi.

## ORI 20.

LI ọdun ti Tartani wá si Aṣdodi, (nigbati Sargoni ọba Assiria rán a,) ti o si ba Aṣdodi jà, ti o si kó o;

2 Li akoko na li Oluwa wi nipa Isaiah ọmọ Amosi, pe, Lọ, bọ aṣọ-ọ̀fọ kuro li ẹgbẹ́ rẹ, si bọ́ bàta rẹ kuro li ẹsẹ rẹ. O si ṣe bẽ, o nrin nihòho ati laibọ̀ bàta.

3 Oluwa si wipe, Gẹgẹ bi Isaiah iranṣẹ mi ti rìn nihòho ati laibọ̀ bàta li ọdun mẹta fun ami ati iyanu lori Egipti ati lori Etiopia;

4 Bẽli ọba Assiria yio kó awọn ara Egipti ni igbèkun ati awọn ara Etiopia ni igbèkun, ọmọde ati arugbo, nihòho ati laibọ̀ bàta, ani ti awọn ti idí wọn nihòho, si itiju Egipti.

5 Ẹ̀ru yio si bà wọn, oju o si tì wọn fun Etiopia ireti wọn, ati fun Egipti ogo wọn.

6 Awọn olugbé àgbegbe okun yio si wi li ọjọ na pe, Kiyesi i, iru eyi ni ireti wa, nibiti awa salọ fun iranlọwọ ki a ba le gbani là kuro li ọwọ́ ọba Assiria: ati bawo li a o si ṣe salà?

## ORI 21.

ỌRỌ-ÌMỌ niti ijù okun. Gẹgẹ bi ãja gusùn ti ikọja lọ; bẽli o ti ijù wá, lati ilẹ ti o li ẹ̀rù.

2 Iran lile li a fi hàn mi; ọ̀dalẹ dalẹ, akoni si nkoni. Goke lọ, iwọ Elamu: doti, iwọ Media; gbogbo imí-ẹdùn inu rẹ̀ li emi ti mu da.

3 Nitorina ni ẹgbẹ́ mi ṣe kun fun irora: irora si ti dì mi mu, gẹgẹ bi irora obirin ti nrọbi: emi tẹ̀ ba nigbati emi gbọ́ ọ: emi dãmu nigbati emi ri i.

4 Ọkàn mi nrò, ẹ̀ru dẹrùba mi: oru ayọ̀ mi li o ti sọ di ìbẹru fun mi.

5 Pèse tabili silẹ, yàn alore, jẹ, mu: dide, ẹnyin ọmọ-alade, ẹ kùn asà nyin.

6 Nitori bayi li Oluwa ti sọ fun mi, Lọ, fi ẹnikan ṣọ ọ̀na, jẹ ki o sọ ohun ti o ri.

7 On si ri kẹkẹ́ pẹlu ẹlẹṣin meji-meji, kẹkẹ́ kẹtẹkẹtẹ, kẹkẹ́ ibakasiẹ; o si fi ibaralẹ tẹtilelẹ gidigidi:

8 On si kigbe pe, kiniun kan: Oluwa mi, nigbagbogbo li emi nduro lori ile-iṣọ li ọsan, a si fi mi si iṣọ mi ni gbogbo oru:

9 Si kiyesi i, kẹkẹ́ enia kan ni mbọ̀ wá yi, pẹlu ẹlẹṣin meji-meji. On si dahun, o si wipe, Babiloni ṣubu, o ṣubu; ati gbogbo ere fifín òriṣa rẹ̀ li o wó mọlẹ.

Digitized by Google

10 Iwọ ìpaka mi, ati ọkà ilẹ ìpaka mi:
eyi ti emi ti gbọ́ lọdọ Oluwa awọn ọmọ-
ọgun, Ọlọrun Israeli li emi ti sọ fun ọ.
11 Ọ̀rọ-ìmọ niti Duma. O ké si mi lati
Seiri wá, Oluṣọ́, oru ti ri? Oluṣọ́ oru ti
ri?
12 Oluṣọ́ wipe, ilẹ nmọ́ bọ̀, alẹ si nlẹ
pẹlu: bi ẹnyin o ba bere, ẹ bere: ẹ pada, ẹ
wá.
13 Ọ̀rọ-ìmọ niti Arabia. Ninu igbó
Arabia li ẹnyin o wọ̀, ẹnyin ẹgbẹ-erò De-
danimu.
14 Awọn olugbé ilẹ Tema bù omi wá
fun ẹniti ongbẹ ngbẹ, onjẹ wọn ni nwọn fi
ṣaju ẹniti nsalọ.
15 Nitori nwọn nsá fun idà, fun idà
fifayọ, ati fun ọrun kikàn, ati fun ibinujẹ
ogun.
16 Nitori bayi li Oluwa ti sọ fun mi, ki
ọdun kan to pe, gẹgẹ bi ọdun alagbaṣe,
gbogbo ogo Kedari yio wọ̀.
17 Iyokù ninu iye awọn tafàtafà, awọn
alagbara ninu awọn ọmọ Kedari yio dinkù:
nitori Oluwa Ọlọrun Israeli ti wi i.

## ORI 22.

ỌRỌ-ÌMỌ niti afonifoji ojuran. Kili o ṣe
ọ nisisiyi, ti iwọ fi gùn ori ile lọ pata-
pata?
2 Iwọ ti o kún fun ìrukerudo, ilu aitòro,
ilu ayọ̀: a kò fi idà pa awọn okú rẹ, bẽni
nwọn kò kú li ogun.
3 Gbogbo awọn alakoso rẹ ti jumọ sa lọ,
awọn tafàtafà ti dì wọn ni igbekun: gbo-
gbo awọn ti a ri ninu rẹ li a dì jọ, ti o ti sa
lati okere wá.
4 Nitorina li emi ṣe wipe, Mu oju kuro
lara mi; emi o sọkun kikoro, má ṣe ãpọn
lati tù mi ni inu, nitori iparun ti o ba
ọmọbirin enia mi.
5 Nitori ọjọ wahála ni, ati itẹmọlẹ, ati
idãmu, nipa Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-ogun
ni afonifoji ojuran, o nwó odi palẹ, o si
nkigbe si oke-nla.
6 Elamu rù apó pẹlu kẹkẹ́ enia ati ẹlẹ-
ṣin, Kiri si nà asà silẹ.
7 Yio si ṣe, afonifoji àṣayan rẹ yio kún
fun kẹkẹ́, awọn ẹlẹṣin yio si tẹ́ ogun niha
ẹnu odi.
8 On si ri iboju Juda, iwọ si wò li ọjọ na
ihamọra ile igbó.
9 Ẹnyin ti ri oju-iho ilu Dafidi pẹlu, pe,
nwọn pọ̀: ẹnyin si gbá omi ikudu isalẹ jọ.
10 Ẹnyin ti kà iye ile Jerusalemu, awọn
ile na li ẹnyin biwó lati mu odi le.
11 Ẹnyin pẹlu ti wà yàra lãrin odi meji
fun omi ikudu atijọ: ṣugbọn ẹnyin kò wò
ẹniti o ṣe e, bẽni ẹ kò si buyìn fun ẹniti o
ṣe e nigbãni,
12 Ati li ọjọ na ni Oluwa, Oluwa awọn
ọmọ-ogun yio pè lati sọkun, ati lati ṣọ̀fọ,
ati lati fá ori, ati lati sán aṣọ ọ̀fọ.
13 Si kiyesi i, ayọ̀ ati inu-didùn, pipa
malũ, ati pipa agutan, jijẹ ẹran, ati mimu
ọti-waini: ẹ jẹ ki a ma jẹ, ki a si ma mu;
nitori ọla li awa o kú.
14 Oluwa awọn ọmọ-ogun sọ li eti mi,
pe, Nitõtọ, a kì yio fọ̀ aiṣedede yi kuro
lara nyin titi ẹnyin o fi kú, li Oluwa,
Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
15 Bayi li Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi, pe, Lọ, tọ olutọju yi lọ, ani tọ Ṣebna
lọ, ti iṣe olori ile,
16 Si wipe, Kili o ni nihin? ati tali o ni
nihin, ti iwọ fi wà ibojì nihin bi ẹniti o wà
ibojì fun ara rẹ̀ nibi giga, ti o si gbẹ́ ibu-
gbé fun ara rẹ̀ ninu apata?
17 Kiyesi i, Oluwa yio fi sisọ agbara sọ
ọ nù, yio si bò ọ mọlẹ.
18 Yio wé ọ li ewé bi ẹni wé lawàni bi
ohun ṣiṣù ti a o fi sọ òko si ilẹ titobi: nibẹ
ni iwọ o kú, ati nibẹ ni kẹkẹ́ ogo rẹ yio jẹ
ìtiju ile oluwa rẹ.
19 Emi o si le ọ jade kuro ni ibujoko rẹ,
yio si wọ́ ọ tilẹ kuro ni ipò rẹ.
20 Yio si ṣe li ọjọ na, ni emi o pè Eli-
akimu iranṣẹ mi ọmọ Hilkiah.
21 Emi o si fi aṣọ-igunwà rẹ wọ̀ ọ, emi
o si fi àmure rẹ dì i, emi o si fi ijọba rẹ le e
li ọwọ́: on o si jẹ baba fun awọn olugbé
Jerusalemu, ati fun ile Juda.
22 Iṣikà ile Dafidi li emi o fi le èjiká rẹ̀:
yio si ṣí, kò si ẹniti yio tì; on o si tì, kò
si si ẹniti yio ṣí.
23 Emi o si kàn a bi iṣó ni ibi ti o le, on
o jẹ fun itẹ ogo fun ile baba rẹ̀.
24 Gbogbo ogo ile baba rẹ̀ ni nwọn o si
fi kọ́ ọ li ọrùn, ati ọmọ ati eso, gbogbo
ohunelò ife titi de ago ọti.
25 Oluwa awọn ọmọ-ogun wipe, Li ọjọ
na, ni a o ṣi iṣó ti a kàn mọ ibi ti o le ni
ipò, a o si ke e lu ilẹ, yio si ṣubu; ẹrù ara
rẹ li a o ké kuro: nitori Oluwa ti sọ ọ.

## ORI 23.

ỌRỌ-ÌMỌ niti Tire. Hu, ẹnyin ọkọ̀ Tarṣi-
ṣi; nitoriti a o sọ ọ di ahoro, tobẹ̃ ti
kò si ile, kò si ibi wiwọ̀: a fi hàn fun wọn
lati ilẹ Kittimu.
2 Ẹ duro jẹ, ẹnyin olugbé erekùṣu; iwọ

Digitized by Google

ẹniti awọn oniṣowo Sidoni, ti nre okun kọja ti kún.

3 Ati nipa omi nla iru Sihori, ikorè odò, ni owo ọdun rẹ̀; on ni ọjà awọn orilẹ ède.

4 Ki oju ki o tì ọ, Iwọ Sidoni: nitori okun ti sọ̀rọ, ani agbara okun wipe, Emi kò rọbi, bẽni emi kò bi ọmọ, bẽli emi kò tọ́ ọdọmọkọnrin dàgba, bẽni emi kò tọ́ wundia dàgba.

5 Gẹgẹ bi ihìn niti Egipti, bẽni ara yio ro wọn goro ni ihìn Tire.

6 Ẹ kọja si Tarṣiṣi; hu, ẹnyin olugbé erekùṣu.

7 Eyi ha ni ilu ayọ̀ fun nyin, ti o ti wà lati ọjọ jọjọ? ẹsẹ on tikara rẹ̀ yio rù u lọ si ọna jijìn rére lati ṣe atipó.

8 Tali o ti gbìmọ yi si Tire, ilu ade, awọn oniṣòwo ẹniti o jẹ ọmọ-alade, awọn alajapá ẹniti o jẹ ọlọla aiye?

9 Oluwa awọn ọmọ-ogun ti pete rẹ̀, lati sọ irera gbogbo ogo di aimọ́, lati sọ gbogbo awọn ọlọla aiye di ẹ̀gan.

10 Là ilẹ rẹ ja bi odò, iwọ ọmọbirin Tarṣiṣi: àmure kò si mọ́.

11 O nà ọwọ́ rẹ̀ jade si oju okun, o mì awọn ijọba: Oluwa ti pa aṣẹ niti Kenaani, lati run agbàra inu rẹ̀.

12 On si wipe, Iwọ kò gbọdọ yọ̀ mọ, iwọ wundia ti a ni lara, ọmọbirin Sidoni; dide rekọja lọ si Kittimu, nibẹ pẹlu iwọ kì yio ri isimi.

13 Wò ilẹ awọn ara Kaldea; awọn enia yi kò ti si ri, titi awọn ara Assiria tẹ̀ ẹ dó fun awọn ti ngbe aginju: nwọn kọ́ ile-iṣọ́ inu rẹ̀, nwọn si kọ́ ãfin inu rẹ̀; on si pa a run.

14 Hu, ẹnyin ọkọ̀ Tarṣiṣi: nitori a sọ agbara nyin di ahoro.

15 Yio si ṣe li ọjọ na, ni a o gbagbe Tire li ãdọrin ọdun, gẹgẹ bi ọjọ ọba kan: lẹhin ãdọrin ọdun ni Tire yio kọrin bi panṣaga obirin.

16 Mu harpu kan, kiri ilu lọ, iwọ panṣaga obirin ti a ti gbagbe; dá orin didùn: kọ orin pupọ̀ ki a le ranti rẹ.

17 Yio si ṣe li ẹhìn ãdọrin ọdun, ni Oluwa yio bẹ̀ Tire wò, yio si yipadà si ọ̀ya rẹ̀, yio si ba gbogbo ijọba aiye yi ti o wà lori ilẹ ṣe àgbere.

18 Ọjà rẹ̀ ati ọ̀ya rẹ̀ yio jẹ mimọ́ si Oluwa: a kì yio fi ṣura, bẽli a ki yio tò o jọ; nitori ọjà rẹ̀ yio jẹ ti awọn ti ngbe iwaju Oluwa, lati jẹ tẹ́ ọrùn, ati fun aṣọ daradara.

## ORI 24.

KIYESI i, Oluwa sọ aiye di ofo, o si sọ ọ di ahoro, o si yi i po, o si tú awọn olugbé inu rẹ̀ ka.

2 Yio si ṣe, bi o ti ri fun awọn enia, bẽli o ri fun alufa; bi o ti ri fun iranṣẹ-kọnrin, bẽni fun oluwa rẹ̀; bi o ti ri fun iranṣẹ-birin, bẽni fun oluwa rẹ̀; bi o ti ri fun olùra, bẽni fun olùta; bi o ti ri fun awinni, bẽni fun atọrọ; bi o ti ri fun agbà elé, bẽni fun ẹniti o san ele fun u.

3 Ilẹ yio di ofo patapata, yio si bajẹ patapata: nitori Oluwa ti sọ ọ̀rọ yi.

4 Ilẹ̀ nṣọ̀fọ o si nṣá, aiye nrù o si nṣá, awọn ẹni giga ilẹ njoro.

5 Ilẹ pẹlu si di aimọ́ li abẹ awọn ti ngbe inu rẹ̀; nitori nwọn ti rú ofin, nwọn pa ilàna dà, nwọn dà majẹmu aiyeraiye.

6 Nitorina ni ẹgún ṣe jẹ ilẹ run, awọn ti ngbe inu rẹ̀ di ahoro: nitorina ni awọn ti ngbe ilẹ jona, enia diẹ li o si kù.

7 Ọti-waini titun nṣọ̀fọ, àjara njoro, gbogbo awọn ti nṣe aríya nkẹdùn.

8 Ayọ̀ tabreti dá, ariwo awọn ti nyọ̀ pin, ayọ̀ harpu dá.

9 Nwọn kì yio fi orin mu ọti-waini mọ́; ọti-lile yio koro fun awọn ti nmu u.

10 A wó ilu rúdurudu palẹ: olukuluku ile li a se, ki ẹnikan má bà wọle.

11 Igbe fun ọti-waini mbẹ ni igboro; gbogbo ayọ̀ ṣú òkunkun, aríya ilẹ na lọ.

12 Idahoro li o kù ni ilu, a si fi iparun lù ẹnu-ibode.

13 Nigbati yio ri bayi li ãrin ilẹ lãrin enia na, bi mimì igi olifi, ati bi pipẽṣẹ eso-àjara nigbati ikorè àjara tán.

14 Nwọn o gbe ohùn wọn soke, nwọn o kọrin nitori ọla-nla Oluwa, nwọn o kigbe kikan lati okun wá.

15 Nitorina yìn Oluwa li ogo ni ilẹ imọlẹ, ani orukọ Oluwa Ọlọrun Israeli li erekùṣu okun.

16 Lati opin ilẹ li awa ti gbọ́ orin, ani ogo fun olododo. Ṣugbọn emi wipe, Iparun mi, iparun mi, egbé ni fun mi! awọn ọ̀dalẹ ti dalẹ: nitõtọ, awọn ọ̀dalẹ dalẹ rekọja.

17 Ibẹ̀ru, ati ọ̀fin, ati ẹgẹ́, wà lori rẹ, iwọ ti ngbe ilẹ-aiye.

18 Yio si ṣe, ẹniti o sá kuro fun ariwo ìbẹru yio jìn sinu ọ̀fin; ati ẹniti o jade lati inu ọ̀fin wá li a o fi ẹgẹ́ mu: nitori awọn ferese lati oke wá ṣi silẹ, ipilẹ ilẹ si mì.

19 Ilẹ di fifọ́ patapata, ilẹ di yíyọ patapata, ilẹ mì-titi.

Digitized by Google

20 Ilẹ yio ta gbọ̀ngbọn sihin sọhun bi
ọ̀mutí, a o si ṣi ni idí bi agọ́; irekọja inu
rẹ̀ yio wọ̀ ọ li ọrùn; yio si ṣubu, kì yio si
dide mọ́.
21 Yio si ṣe li ọjọ na, Oluwa yio bẹ̀
ogun awọn ẹni-giga ni ibi-giga wò, ati
awọn ọba aiye li aiye.
22 A o si ko wọn jọ pọ̀, bi a iti kó ara
tubu jọ sinu ihò, a o tì wọn sinu tubu,
lẹhin ọjọ pupọ̀ li a o si bẹ̀ wọn wò.
23 Nigbana li a o dãmu oṣupa, oju yio
si tì õrùn, nigbati Oluwa awọn ọmọ-ogun
yio jọba li oke Sioni ati ni Jerusalemu,
ogo yio si wà niwaju awọn alàgba rẹ̀.

## ORI 25.

OLUWA, iwọ li Ọlọrun mi; emi o gbe
ọ ga emi o yìn orukọ rẹ; nitori iwọ
ti ṣe ohun iyanu; ìmọ igbani, ododo ati
otitọ ni.
2 Nitori iwọ ti sọ ilu kan di okiti; iwọ
ti sọ ilu olodi di iparun: ãfin awọn alejo,
kò jẹ ilu mọ́; a kì yio kọ́ ọ mọ.
3 Nitorina ni awọn alagbara enia yio
yìn ọ li ogo, ilu orilẹ-ède ti o ni ibẹ̀ru yio
bẹ̀ru rẹ.
4 Nitori iwọ ti jẹ agbara fun talaka,
agbara fun alaini ninu iṣẹ́ rẹ̀, ãbo kuro
ninu ìji, ojiji kuro ninu oru, nigbati ẹfũfu
lile awọn ti o ni ibẹ̀ru dabi ìji lara ogiri.
5 Iwọ o mu ariwo awọn alejo rọlẹ, gẹgẹ
bi oru nibi gbigbẹ; ani oru pẹlu ojiji
awọsanma: a o si rẹ̀ orin-ayọ̀ awọn ti o ni
ibẹ̀ru silẹ.
6 Ati ni oke-nla yi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun yio sè asè ohun abọ́pa fun gbogbo
orilẹ-ède, asè ọti-waini lori gẹ̀dẹ̀gẹ́dẹ, ti
ohun abọpa ti o kún fun ọra, ti ọti-waini
ti o tòro lori gẹ̀dẹ̀gẹ́dẹ.
7 Li oke-nla yi on o si pa iboju ti o bò
gbogbo enia loju run, ati iboju ti a nà bò
gbogbo orilẹ-ède.
8 On o gbe iku mì lailai; Oluwa Jeho-
fah yio nù omije nù kuro li oju gbogbo
enia; yio si mu ẹ̀gan enia rẹ̀ kuro ni
gbogbo aiye: nitori Oluwa ti wi i.
9 A o si sọ li ọjọ na pe, Wò o, Ọlọrun
wa li eyi; awa ti duro de e, on o si gbà
wa là: Oluwa li eyi: awa ti duro de e,
awa o ma yọ̀, inu wa o si ma dùn ninu
igbala rẹ̀.
10 Nitori li oke-nla yi ni ọwọ́ Oluwa
yio simi, yio si tẹ̀ Moabu labẹ rẹ̀, ani gẹgẹ
bi ãti tẹ̀ koriko mọlẹ fun ãtan.
11 Yio si nà ọwọ́ rẹ̀ jade li ãrin wọn,
gẹgẹ bi ọ̀mwẹ iti nà ọwọ́ rẹ̀ jade lati wẹ̀:
on o si rẹ̀ igberaga wọn silẹ pọ̀ pẹlu ikogun
ọwọ́ wọn.
12 Odi alagbara odi giga odi rẹ li on o
wó lulẹ, yio rẹ̀ ẹ silẹ, yio mu u wá ilẹ, ani
sinu ekuru.

## ORI 26.

LI ọjọ na li a o kọ orin yi ni ilẹ Juda;
Awa ní ilu agbara; igbala li Ọlọrun
yio yàn fun odi ati ãbo.
2 Ẹ ṣi ilẹkun bodè silẹ, ki orilẹ-ède
ododo ti nṣọ́ otitọ ba le wọ̀ ile.
3 Iwọ o pa a mọ li alafia pipé, ọkàn
ẹniti o simi le ọ: nitoriti o gbẹkẹle ọ.
4 Ẹ gbẹkẹlẹ Oluwa titi lai: nitori Oluwa
Jehofa li apata aiyeraiye:
5 Nitori o rẹ̀ awọn ti ngbe oke giga silẹ;
ilu giga, o mu u wálẹ; o mu u wálẹ; ani
si ilẹ; o mu u de inu ekuru.
6 Ẹsẹ yio tẹ̀ ẹ mọlẹ, ani ẹsẹ awọn talaka,
ati iṣísẹ awọn alaini.
7 Ọna awọn olõtọ ododo ni: iwọ, olõtọ-
julọ, ti wọ̀n ipa-ọ̀na awọn olõtọ.
8 Nitõtọ, Oluwa, li ọ̀na idajọ rẹ, li awa
duro de ọ: ifẹ ọkàn wa ni si orukọ rẹ, ati
si iranti rẹ.
9 Ọkàn mi li emi fi ṣe afẹ́ri rẹ li oru;
nitõtọ, pẹlu ẹmi mi ninu mi li emi o wá
ọ ni kutùkutù; nitori nigbati idajọ rẹ mbẹ
ni ilẹ, awọn ti mbẹ li aiye yio kọ́ ododo.
10 Bi a ba fi ojurere hàn enia buburu,
kì yio kọ́ ododo: ni ilẹ iduroṣinṣin li on
o hùwa aiṣõtọ, kì yio si ri ọlanla Oluwa.
11 Oluwa, ọwọ́ rẹ gbe soke, nwọn kì yio
ri, ṣugbọn nwọn o ri, oju o si tì wọn nitori
ilara wọn si awọn enia; nitõtọ, iná awọn
ọta rẹ yio jẹ wọn run.
12 Oluwa, iwọ o fi idi alafia mulẹ fun
wa: pẹlupẹlu nitori iwọ li o ti ṣe gbogbo
iṣẹ wa fun wa.
13 Oluwa Ọlọrun wa, awọn oluwa miran
lẹhin rẹ ti jọba lori wa: ṣugbọn nipa rẹ
nikan li awa o da orukọ rẹ sọ.
14 Awọn okú, nwọn kì yio yè; awọn
ti ngbe isà-okú, nwọn kì yio dide; nitorina
ni iwọ ṣe bẹ̀ wọn wò ti o si pa wọn run,
ti o si mu ki gbogbo iranti wọn parun.
15 Iwọ ti mu orilẹ-ède bi si i, Oluwa,
iwọ ti mu orilẹ-ède bi si i; iwọ ti di ẹni-
ãyìn li ogo: iwọ ti sún gbogbo ãlà siwaju.
16 Oluwa, ninu wahala ni nwọn wá ọ,
nwọn gbadura wúyẹwuyẹ nigbati ibawi rẹ
wà lara wọn.
17 Gẹgẹ bi aboyun, ti o sunmọ akoko
ibi rẹ̀, ti wà ni irora, ti o si kigbe ninu
irora rẹ̀; bẹ̃li awa ti wà li oju rẹ, Oluwa.

Digitized by Google

18 Awa ti loyun, awa ti wà ni irora, o
si dabi ẹnipe awa ti bi ẹfũfu; awa kò ṣiṣẹ
igbala kan lori ilẹ, bẹ̃ni awọn ti ngbe aiye
kò ṣubu.
19 Awọn okú rẹ yio yè, okú mi, nwọn
o dide. Ẹ ji, ẹ si kọrin, ẹnyin ti ngbe inu
ekuru: nitori ìri rẹ ìri ewebẹ̀ ni, ilẹ yio
si sọ awọn okú jade.
20 Wá, enia mi, wọ̀ inu iyẹ̀wu rẹ lọ, si
se ilẹkun rẹ mọ ara rẹ: fi ara rẹ pamọ bi
ẹnipe ni iṣẹ́ju kan, titi ibinu na fi rekọja.
21 Nitorina, kiye si i, Oluwa ti ipò rẹ̀
jade lati bẹ̀ aiṣedede ẹniti ngbe ori ilẹ wò
lori ilẹ; ilẹ pẹlu yio fi ẹ̀jẹ rẹ̀ hàn, kì yio
si bò okú rẹ̀ mọ.

## ORI 27.

LI ọjọ na li Oluwa yio fi idà rẹ̀ mimú ti
o tobi, ti o si wuwo bá lefiatani ejò
ti nfò wi, ati lefiatani ejò wiwọ́ nì; on o
si pa dragoni ti mbẹ̀ li okun.
2 Li ọjọ na ẹ kọrin si i, Ajàra ọti-waini
pipọ́n.
3 Emi Oluwa li o ṣọ ọ: emi o bù omi
wọ́n ọ nigbakugba: ki ẹnikẹni má ba bà
a jẹ, emi o ṣọ ọ ti oru ti ọsan.
4 Irunú kò si ninu mi: tani le doju
pantiri ẹlẹgun ati ẹgun kọ mi li ogun jijà?
emi iba là wọn kọja, emi iba fi wọn jona
ṣọkan pọ̀.
5 Tabi jẹ ki o di agbara mi mu, ki o ba
le ba mi lajà; yio si ba mi lajà.
6 Yio mu ki awọn ti o ti Jakobu wá ta
gbòngbo: Israeli yio tanna yio si rudi, yio
si fi eso kún oju gbogbo aiye.
7 On ha lù u bi o ti nlu awọn ti o lù u?
a ha pa a gẹgẹ bi pipa awọn ti on pa?
8 Niwọ̀n-niwọ̀n, nigba itì jade rẹ̀, iwọ o
ba a wi: on ṣi ẹfũfu-ile rẹ̀ ni ipò li ọjọ ẹfũfu
ilà-õrùn.
9 Nitorina nipa eyi li a o bò ẹ̀ṣẹ Jakobu
mọlẹ: eyi si ni gbogbo eso lati mu ẹ̀ṣẹ rẹ̀
kuro; nigbati on gbe okuta pẹpẹ kalẹ bi
okuta ẹfun ti a lù wẹwẹ, igbo ati ere-õrùn
kì yio dide duro.
10 Nitori ilu-olodi yio di ahoro, a o si
kọ̀ ibugbé silẹ, a o si fi i silẹ bi aginju:
nibẹ ni ọmọ-malu yio ma jẹ̀, nibẹ ni yio si
dubulẹ, yio si jẹ ẹka rẹ̀ run.
11 Nigbati ẹka inu rẹ̀ ba rọ, a o ya wọn
kuro: awọn obirin de, nwọn si tẹ̀ iná bọ̀
wọn: nitori alaini oye enia ni nwọn: ni-
torina ẹniti o dá wọn kì yio ṣãnu fun wọn,
ẹniti o si mọ wọn kì yio fi ojurere hàn wọn.
12 Yio si ṣe li ọjọ na, Oluwa yio ja eso
kuro ni ibu odò si iṣàn Egipti, a o si ṣà
nyin jọ li ọkọkan, ẹnyin ọmọ Israeli.
13 Yio si ṣe li ọjọ na, a o fun ipè nla,
awọn ti o mura lati ṣegbe ni ilẹ Assiria yio
si wá, ati awọn aṣátì ilẹ Egipti, nwọn o si
sìñ Oluwa ni oke mimọ ni Jerusalemu.

## ORI 28.

EGBE ni fun ade igberaga, fun awọn
ọmuti Efraimu, ati fun itàna rirọ ti
ogo ẹwà rẹ̀, ti o wà lori afonifoji ọlọra ti
awọn ti ọti-waini pa.
2 Kiye si i, Oluwa ni ẹnikan alagbara
ati onipá, bi ẹfũfu lile, yiyin, ati ìji iparun,
bi iṣàn-omi nla akúnya, yio fi ọwọ́ bì ṣubu
sori ilẹ.
3 Ade igberaga, awọn ọmuti Efraimu, li
a o fi ẹsẹ tẹ̀ mọlẹ:
4 Ati ogo ẹwà, ti o wà lori afonifoji ọlọra,
yio jẹ itana rirọ, gẹgẹ bi eso ti o yara ṣaju
igba ikore; eyiti nigbati ẹniti o ba nwò o
ba ri, nigbati o wà li ọwọ́ rẹ̀ sibẹ, o gbe e
mì.
5 Li ọjọ na li Oluwa awọn ọmọ-ogun yio
jẹ ade ogo, ati ade ẹwà fun iyokù awọn
enia rẹ̀,
6 Ati ẹmi idajọ fun awọn ẹniti o joko ni
idajọ, ati agbara fun awọn ti o le ogun padà
si ibode.
7 Ṣugbọn awọn pẹlu ti ti ipa ọti-waini
ṣìna, ati nipa ọti-lile nwọn ti ṣako; alufa
ati wolĩ ti ṣìna nipa ọti-lile, ọti-waini mu
wọn daradara, nwọn di aṣako nipa ọti-
lile, nwọn ṣìna ninu iran, nwọn kọsẹ ni
idajọ.
8 Nitori gbogbo tabili li o kún fun ẽbi
ati ẹgbin, kò si ibi ti o mọ́.
9 Tani on o kọ́ ni ìmọ? ati tani on o fi
oye ẹkọ́ yé? awọn ẹniti a wọ́n li ẹnu-ọmú,
ti a si já li ẹnu ọyàn.
10 Nitori aṣẹ le aṣẹ, aṣẹ le aṣẹ; ẹsẹ le
ẹsẹ, ẹsẹ le ẹsẹ; diẹ nihin, diẹ lọhun:
11 Nitori nipa ète ẹlẹyà ati ni ède miran
li on o fi bá enia wọnyi sọ̀rọ.
12 Si ẹniti on wipe, Eyi ni isimi, ẹnyin
ìba mu awọn alãrẹ̀ simi; eyi si ni itura:
sibẹ nwọn kì yio gbọ́.
13 Nitorina ọ̀rọ Oluwa jẹ aṣẹ le aṣẹ, aṣẹ
le aṣẹ fun wọn: ẹsẹ le ẹsẹ, ẹsẹ le ẹsẹ; diẹ
nihin, diẹ lọhun: ki nwọn ba le lọ, ki nwọn
si ṣubu sẹhin, ki nwọn si ṣẹ́, ki a si dẹ wọn,
ki a si mu wọn.
14 Nitorina ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, ẹnyin
ẹlẹgàn, ti nṣe akoso awọn enia yi ti mbẹ
ni Jerusalemu.
15 Nitori ẹnyin ti wipe, Awa ti ba ikú

Digitized by Google

da majẹmu, a si ti ba ipò-okú mulẹ: nigbati pàṣan gigun yio là a já, kì yio de ọdọ wa: nitori awa ti fi eké ṣe ãbo wa, ati labẹ irọ́ li awa ti fi ara wa pamọ:

16 Nitorina bayi li Oluwa Jehofah wi, pe, Kiyesi i, emi gbe okuta kan kalẹ ni Sioni fun ipilẹ, okuta ti a dán wò, okuta igun-ile iyebiye, ipilẹ ti o daju: ẹniti o gbagbọ kí yio sá.

17 Idajọ li emi o fi le ẹsẹ pelu, ati ododo li emi o fi lé òṣuwọn: yinyín yio gbá ãbo eke lọ, omi o si kún bò ibi isasi mọlẹ.

18 Majẹmu nyin ti ẹ ba ikú dá li a o sọ di asan, imulẹ nyin pẹlu ipò-okú kì yio duro; nigbati paṣán gigun yio rekọja; nigbana ni on o tẹ̀ nyin mọlẹ.

19 Niwọn igbati o ba jade lọ ni yio mu nyin: nitori ni gbogbo owurọ ni yio rekọja, li ọsan ati li oru: kiki igburo rẹ̀ yio si di ijaiyà.

20 Nitori akete kuru jù eyiti enia le nà ara rẹ̀ si, ati ibora kò ni ibò to eyi ti on le fi bò ara rẹ̀.

21 Nitori Oluwa yio dide bi ti oke Perasimu, yio si binu gẹgẹ bi ti afonifoji Gibeoni, ki o ba le ṣe iṣẹ rẹ̀, iṣẹ àrà rẹ̀; yio si mu iṣe rẹ̀ ṣẹ, ajeji iṣe rẹ̀.

22 Njẹ nitorina, ẹ máṣe jẹ ẹlẹgàn, ki a má ba sọ ìde nyin di lile; nitori emi ti gbọ́ iparun lati ọdọ Oluwa, Oluwa awọn ọmọ-ogun wá, ti o ti pinnu lori gbogbo ilẹ.

23 Ẹ fetisilẹ, ẹ si gbọ́ ohùn mi: ẹ tẹtilelẹ, ẹ si gbọ́ ọ̀rọ mi.

24 Gbogbo ọjọ ni agbẹ̀ ha nroko lati gbìn? on o ha ma tú, a si ma fọ́ ilẹ rẹ̀ bi?

25 Nigbati on ti tẹ́ oju rẹ̀ tan, on kò ha nfunrugbìn dili, ki o si fọn irugbìn kummini ka, ki o gbìn alikama lẹsẹ-ẹsẹ, ati barle ti a yàn, ati spelti nipò rẹ̀?

26 Nitori Ọlọrun rẹ̀ kọ́ ọ lati ni oye, o tilẹ kọ́ ọ.

27 Nitori a kò fi ohun-elò pakà dili, bẽni a kì iyí kẹkẹ́ kiri lori kummini; ṣugbọn ọpá li a ifi pa dili jade, ọgọ li a si fi lù kummini.

28 Akara agbado li a lọ̀; on kò le ma pa a titi, bẽni kò fi kẹkẹ́-ẹrù fọ́ ọ, bẽni kì ifi awọn ẹlẹṣin rẹ̀ tẹ̀ ẹ.

29 Eyi pẹlu ti ọdọ Oluwa awọn ọmọ-ogun wá, ẹniti o kún fun iyanu ni ìmọ, ti o tayọ ni iṣe.

## ORI 29.

EGBE ni fun Arieli, fun Arieli, ilu ti Dafidi ti ngbe! ẹ fi ọdun kún ọdun; jẹ ki wọn pa ẹran rubọ.

2 Ṣugbọn emi o pọ́n Arieli loju, àwẹ on ibanujẹ yio si wà; yio si dabi Arieli si mi.

3 Emi o si dótì ọ yika, emi o si wà odi tì ọ, emi o si mọ odi giga tì ọ.

4 A o si rẹ̀ ọ silẹ, iwọ o sọ̀rọ lati ilẹ jade, ọ̀rọ rẹ yio rẹ̀lẹ lati inu ekuru wá, ohùn rẹ yio si dabi ti ẹnikan ti o li ẹmi àfọṣẹ lati ilẹ jade, ọ̀rọ rẹ yio si dún lati inu erupẹ ilẹ wá.

5 Ọpọlọpọ awọn ọtá rẹ yio dabi ekuru lẹ́bulẹ́bu, ọpọlọpọ aninilara rẹ yio dabi ìyangbo ti o kọja lọ: lõtọ, yio ri bẹ̃ nisisiyi lojiji.

6 Ãrá, ìsẹlẹ, ati iró nla, pẹlu ìji on ẹfúfu, ati ọwọ́ ajonirun iná ni a o fi bẹ̀ ọ wò lati ọdọ Oluwa awọn ọmọ-ogun wá.

7 Bi alá iran oru li ọ̀pọlọpọ awọn orilẹ-ède ti mba Arieli jà yio ri; gbogbo ẹniti o bá ati on, ati odi agbara rẹ̀ jà, ti nwọn si pọ́n ọ loju.

8 Yio si dabi igbati ẹni ebi npa nla alá; si wo o, o njẹun; ṣugbọn o ji, ọkàn rẹ̀ si ṣofo: tabi bi igbati ẹniti ongbẹ ngbẹ nla alá, si wo o, o nmu omi, ṣugbọn o ji, si wo o, o dáku, ongbẹ si ngbẹ ọkàn rẹ̀; gẹgẹ bẹ̃ ni gbogbo ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède yio ri, ti mba oke Sioni jà.

9 Mu ara duro jẹ, ki ẹnu ki o yà nyin; ẹ fọ́ ara nyin loju, ẹ si fọju: nwọn mu amupara; ṣugbọn kì iṣe fun ọti-waini, nwọn nta gbọngbọ́n, ṣugbọn kì iṣe fun ohun mimu lile.

10 Nitori Oluwa dà ẹmi orun ajìka lù nyin, o si se nyin li oju: awọn wolĩ ati awọn olori awọn ariran nyin li o bò li oju.

11 Iran gbogbo si dabi ọ̀rọ iwe kan fun nyin ti a dí, ti a fi fun ẹnikan ti o mọ̀ ọ kà, wipe, Emi bẹ̀ ọ, ka eyi, ti o si wipe, emi kò le ṣe e; nitori a ti dí i.

12 A si fi iwe na fun ẹniti kò mọ̀ iwe, wipe, Emi bẹ̀ ọ, kà eyi, on si wipe, emi kò mọ̀ iwe.

13 Nitorina Oluwa wipe, Niwọ̀n bi awọn enia yi ti nfi ẹnu wọn fà mọ mi, ti nwọn si nfi etè wọn yìn mi, ṣugbọn ti ọkàn wọn jìna si mi, ti nwọn si bẹru mi nipa ilana enia ti a kọ́ wọn.

14 Nitorina, Kiye si i, emi o ma ṣe iṣẹ iyanu lọ lãrin awọn enia yi, ani iṣẹ iyanu ati ajeji: ọgbọ́n awọn ọlọgbọ́n wọn yio si ṣegbe, oye awọn amoye wọn yio si lumọ́.

15 Egbe ni fun awọn ti nwá ọ̀na lati fi ipinnu wọn pamọ buruburu kuro loju Oluwa, ti iṣẹ wọn si wà li okunkun, ti nwọn si wipe, Tali o ri wa? tali o mọ̀ wa?

16 A, iyipo nyin! a ha le kà amọ̀koko

Digitized by Google

si bi amọ̀: ti iṣẹ lè wi fun ẹniti o ṣe e pe,
On kò ṣe mi? ohun ti a mọ le wi fun ẹniti
o mọ ọ pe, On kò moye?
17 Kò ha ṣe pe ìgba diẹ kiun si i, a o sọ
Lebanoni di ọgbà eleso, ati ọgbà eleso li a o
kà si bi igbo?
18 Ati li ọjọ na awọn aditi yio si gbọ́
ọ̀rọ iwe nì, awọn afọju yio si riran lati inu
owúsuwusù, ati lati inu okunkun.
19 Ayọ̀ awọn onirẹlẹ yio bí si i ninu
Oluwa, ati inu awọn talaka ninu awọn
enia yio si dùn ninu Ẹni-Mimọ Israeli.
20 Nitori a sọ aninilara na di asan, a
si pa ẹlẹgàn run, a si ké gbogbo awọn ti
nṣọ́ aiṣedede kuro.
21 Ẹniti o dá enia li ẹbi nitori ọ̀rọ kan,
ti nwọn dẹkùn silẹ fun ẹniti o baniwi ni
ẹnubodè, ti nwọn si tì olododo si apakan,
si ibi ofo.
22 Nitorina bayi li Oluwa, ẹniti o rà
Abrahamu pada wi, pe, niti ile Jakobu,
oju kì yio tì Jakobu mọ, bẹ̃ni oju rẹ̀ kì yio,
yipada mọ.
23 Ṣugbọn nigbati on nri awọn ọmọ rẹ̀,
iṣe ọwọ́ mi, li ãrin rẹ̀, nwọn o yà orukọ mi
si mimọ́, nwọn o si yà Ẹni-Mimọ Jakobu
nì si mimọ́, nwọn o si bẹ̀ru Ọlọrun Israeli.
24 Awọn pẹlu ti o ṣinà nipa ẹmi, oye
yio wá yé wọn, ati awọn ti nsọ bótibòti
yio kọ́ ẹkọ́.

## ORI 30.

OLUWA wipe, egbé ni fun awọn ọlọ̀tẹ
ọmọ, ti nwọn gbà ìmọ, ṣugbọn kì iṣe ati
ọdọ mi; ti nwọn si mulẹ, ṣugbọn kì iṣe
nipa ẹmi mi, ki nwọn ba le fi ẹ̀ṣẹ kún ẹ̀ṣẹ:
2 Ti nwọn nrìn lọ si Egipti, ṣugbọn ti
nwọn kò bere li ẹnu mi; lati mu ara wọn
le nipa agbara Farao, ati lati gbẹkẹle ojiji
Egipti!
3 Nitorina ni agbara Farao yio ṣe jẹ
itiju nyin, ati igbẹkẹle ojiji Egipti yio jẹ
idãmu nyin.
4 Nitori awọn olori rẹ̀ wà ni Soani, awọn
ikọ̀ rẹ̀ de Hanesi.
5 Oju awọn enia kan ti kò li ère fun
wọn tilẹ tì wọn, ti kò le ṣe iranwọ, tabi
anfani, bikoṣe itiju ati ẹ̀gan pẹlu.
6 Ọ̀rọ-ìmọ niti awọn ẹranko gusu: sinu
ilẹ wahala on àrodun, nibiti akọ ati abo
kiniun ti wá, pamọlẹ ati ejò-ina ti nfò,
nwọn o rù ọrọ̀ wọn li ejika awọn ọmọ kẹtẹ-
kẹtẹ, ati iṣura wọn lori iké awọn ràkumi,
sọdọ awọn enia kan ti kò li ère.
7 Egipti yio ṣe iranwọ lasan, kò si ni
lari: nitorina ni mo ṣe kigbe pè e ni,
Rahabu ti o joko jẹ.
8 Nisisiyi lọ, kọ ọ niwaju wọn si walã
kan, si kọ ọ sinu iwe kan, ki o le jẹ fun
igbà ti mbọ̀ lai ati lailai:
9 Pe, ọlọ̀tẹ enia ni awọn wọnyi, awọn
ọmọ eké, awọn ọmọ ti kò fẹ igbọ́ ofin
Oluwa:
10 Ti nwọn wi fun awọn ariran pe,
Máṣe riran; ati fun awọn wolĩ pe, Má
sọtẹlẹ ohun ti o tọ́ fun wa, sọ nkan didùn
fun wa, sọ asọtẹlẹ itanjẹ.
11 Kuro li ọna na, yẹ̀ kuro ni ipa na,
mu ki Ẹni-Mimọ Israeli ki o dẹkun kuro
niwaju wa.
12 Nitorina bayi li Ẹni-Mimọ Israeli wi,
Nitoriti ẹnyin gàn ọ̀rọ yi, ti ẹnyin si gbẹ-
kẹle ininilara on ìyapa, ti ẹnyin si gbe ara
nyin lé e;
13 Nitorina ni aiṣedede yi yio ri si nyin
bi odi yiya ti o mura ati ṣubu, ti o tiri sode
lara ogiri giga, eyiti wiwó rẹ̀ de lojijì, loju-
kanna.
14 Yio si fọ́ ọ bi fifọ́ ohun-èlo amọ̀ ti a
fọ́ tútu; ti a kò dasi: tobẹ̃ ti a kì yio ri
apãdi kan ninu ẹfọ́ rẹ̀ lati fi fọn iná li oju
ãrò, tabi lati fi bù omi ninu ikudu.
15 Nitori bayi ni Oluwa Jehofah, Ẹni-
Mimọ Israeli wi; Ninu pipada on sisimi li
a o fi gbà nyin là; ninu didakẹjẹ ati gbi-
gbẹkẹle li agbara nyin wà; ṣugbọn ẹnyin
kò fẹ.
16 Ṣugbọn ẹnyin wipe, Bẹ̃kọ; nitori
ẹṣin li a o fi sá; nitorina li ẹnyin o ṣe sá:
ati pe, Awa o gùn eyi ti o lè sare; nitorina
awọn ti yio lepa nyin yio lè sare.
17 Ẹgbẹrun yio sá ni ibawi ẹnikan; ni
ibawi ẹni marun li ẹnyin o sá: titi ẹnyin o
fi kù bi àmi lori oke-nla, ati bi asia lori
oke.
18 Nitorina ni Oluwa yio duro, ki o le
ṣe ore fun nyin, ati nitori eyi li o ṣe ga, ki
o le ṣe iyọ́nu si nyin: nitori Oluwa li
Ọlọrun idajọ: ibukun ni fun gbogbo awọn
ti o duro dè e.
19 Nitori awọn enia Sioni yio gbe Jeru-
salemu, iwọ kì yio sọkun mọ: yio ṣanu fun
ọ gidigidi nigbati iwọ ba nkigbe; nigbati
on ba gbọ́ ọ, yio dá ọ lohùn.
20 Oluwa yio si fi onjẹ ipọnju, ati omi
inira fun nyin, awọn olukọ́ni rẹ kì yio lumọ́
mọ, ṣugbọn oju rẹ yio ri olukọ́ni rẹ:
21 Eti rẹ o si gbọ́ ọ̀rọ kan lẹhin rẹ, wipe,
Eyiyi li ọ̀na, ẹ ma rín ninu rẹ̀, nigbati
ẹnyin bá yi si apa ọtún, tabi nigbati ẹnyin
bá yi si apa òsi.

Digitized by Google

22 Ẹnyin o si sọ ibora ere fadaka nyin
wọnni di aimọ́, ati ọṣọ́ ere wura didà nyin
wọnni: iwọ o sọ wọn nù bi ohun-aimọ́,
iwọ o si wi fun u pe, Kuro nihinyi.
23 On o si rọ̀ òjo si irugbin rẹ ti iwọ ti
fọ́n si ilẹ: ati onjẹ ibísi ilẹ, yio li ọrá yio
si pọ̀: li ọjọ na ni awọn ẹran rẹ yio ma jẹ̀
ni pápa oko nla.
24 Awọn akọ-malu pẹlu, ati awọn ọmọ
kẹtẹkẹtẹ ti ntulẹ yio jẹ oko didùn, ti a ti
fi kọ̀nkọsọ ati atẹ fẹ.
25 Ati lori gbogbo oke-nla giga, ati lori
gbogbo oke kékèké ti o ga, ni odò ati ipa-
omi yio wà li ọjọ pipa nla, nigbati ile-iṣọ́
wọnni bá wó.
26 Imọ́lẹ oṣupa yio si dabi imọ́lẹ õrun,
imọ́lẹ õrùn yio si ràn ni iwọ̀n igbà meje, bi
imọ́lẹ ọjọ meje, li ọjọ ti Oluwa dí yiya awọn
enia rẹ̀, ti o si ṣe àwotán ọgbẹ ti a ṣá wọn.
27 Kiyesi i, orukọ Ọluwa mbọ̀ lati ọ̀na
jijin wá, ibinu rẹ̀ si njo, ẹrù rẹ̀ si wuwo:
ète rẹ̀ si kún fun ikọnnu, ati ahọn rẹ̀ bi
ajonirun iná:
28 Ẽmi rẹ̀ bi kikun omi, yio si de ãrin-
meji ọrùn, lati fi kọ̀nkọsọ kù awọn orilẹ-
ède: ijanu yio si wà li ẹ̀rẹkẹ́ awọn enia,
lati mu wọn ṣina.
29 Ẹnyin o li orin kan, gẹgẹ bi igbati a
nṣe ajọ li oru; ati didùn inu, bi igbati
ẹnikan fun fère lọ, lati wá si oke-nla Oluwa,
sọdọ Apata Israeli.
30 Oluwa yio si mu ki a gbọ́ ohùn ogo
rẹ̀, yio si fi isọkalẹ apá rẹ̀ hàn pẹlu ikọnnu
ibinu rẹ̀, ati pẹlu ọwọ́ ajonirun iná, pẹlu
ifúnka, ati ijì, ati yinyín.
31 Nitori nipa ohùn Oluwa li a o fi lù
awọn ara Assiria bo ilẹ, ti o fi kùmọ lù.
32 Ati nibi gbogbo ti paṣán ti a yàn ba
kọja si, ti Oluwa yio fi lé e, yio ṣe pẹlu
tabreti ati dùru: yio si fi irọ́kẹ̀kẹ ogun bá
a jà.
33 Nitori a ti yàn Tofeti lati igbà atijọ;
nitõtọ, ọba li a ti pèse rẹ̀ fun; o ti ṣe e ki
o jìn, ki o si gbòro: okiti rẹ̀ ni iná ati igi
pupọ; ẽmi Oluwa, bi iṣàn brimstoni, ntàn
iná ràn a.

## ORI 31.

EGBE ni fun awọn ti o sọkalẹ lọ si Egipti
fun iranlọwọ; ti nwọn gbẹkẹle ẹṣin,
ti nwọn gbiyèle kẹkẹ́, nitoriti nwọn pọ̀:
nwọn si gbẹkẹle ẹlẹṣin nitoriti nwọn li
agbara jọjọ; ṣugbọn ti nwọn kò wò Ẹni-
Mimọ Israeli, nwọn kò si wá Oluwa!
2 Ṣugbọn on gbọ́n pẹlu, o si mu ibi wá,
kì yio si dá ọ̀rọ rẹ̀ padà: on si dide si ile
awọn oluṣe buburu, ati si iranlọwọ awọn ti
nṣiṣẹ aiṣedede.
3 Nitori enia li awọn ara Egipti, nwọn
kì iṣe Ọlọrun; ẹran li awọn ẹṣin wọn, nwọn
kì si iṣe ẹmi. Oluwa yio si nà ọwọ́ rẹ̀, ki
ẹniti nràn ni lọwọ ba le ṣubu, ati ki ẹniti
a nràn lọwọ ba lè ṣubu, gbogbo wọn o
jùmọ ṣegbe.
4 Nitori bayi li Oluwa ti wi fun mi pe,
Gẹgẹ bi kiniun ati ẹgbọ̀rọ kiniun ti nkùn
si ohun-ọdẹ rẹ̀, nigbati a npè ọpọlọpọ oluṣọ́-
agutan jade wá si i, ti on kò bẹ̀ru ohùn
wọn, ti kò si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ fun ariwo wọn:
bẽli Oluwa awọn ọmọ-ogun yio sọkalẹ wá
lati jà lori okè-nla Sioni, ati lori oke kékè-
ké rẹ̀.
5 Gẹgẹ bi ẹiyẹ iti fi iyẹ́ apa ṣe, bẽni
Oluwa awọn ọmọ-ogun yio dãbòbo Jerusa-
lemu; ni didãbòbo o pẹlu yio si gbà a silẹ;
ni rirekọja on o si dá a si.
6 Ẹ yipadà si ẹniti ẹ ti nṣọ̀tẹ si gidigidi,
ẹnyin ọmọ Israeli.
7 Nitori li ọjọ na ni olukuluku enia yio
jù ere fadaka rẹ̀, ati ere wura rẹ̀ nù, ti ọwọ́
ẹnyin tikara nyin ti ṣe fun ẹ̀ṣẹ fun nyin.
8 Nigbana ni ara Assiria na yio ṣubu
nipa idà, ti kì iṣe nipa idà ọkọnrin, ati
idà ti ki iṣe ti enia yio jẹ ẹ: ṣugbọn on o
sá kuro niwaju idà, awọn ọdọmọkọnrin rẹ̀
yio ma sìn.
9 Apata rẹ̀ yio kọja lọ fun ẹ̀ru, awọn
olori rẹ̀ yio bẹru asia na, ni Oluwa wi,
ẹniti iná rẹ̀ wà ni Sioni, ati ileru rẹ̀ ni
Jerusalemu.

## ORI 32.

KIYESI i, ọba kan yio jẹ li ododo, awọn
olori yio fi idajọ ṣe akoso.
2 Ẹnikan yio si jẹ bi ibi ilumọ́ kuro loju
ẹfũfu, ati ãbo kuro lọwọ ijì; bi odo-omi ni
ibi gbigbẹ, bi ojiji apata nla ni ilẹ gbigbẹ.
3 Oju awọn ẹniti o riran kì yio ṣe baibai,
ati eti awọn ti o ngbọ́ yio tẹ́ silẹ.
4 Ọkàn awọn oniwàduwàdu yio mọ̀ oye,
ahọn awọn akolòlo yio sọ̀rọ kedere.
5 A kì yio tun pè eniakenia ni ọ̀sọnú
mọ, bẽni a kì yio pe oloju-kikoro ni oninu-
re mọ.
6 Nitori eniakenia yio ma sọ isọkusọ,
ọkàn rẹ̀ yio si ma ṣiṣẹ aiṣedede, lati ṣe
agabàgebe, ati lati ṣì ọ̀rọ sọ si Oluwa, lati
sọ ọkàn ẹniti ebi npa di ofo, ati lati mu ki
ohun-mimu awọn ti ongbẹ ngbẹ ki o dá.
7 Ibi ni gbogbo ohun-elò ọ̀sọnú jẹ pẹlu:
on gbà èro buburu, lati fi ọ̀rọ eke pa talaka
run, bi alaini tilẹ nsọ õtọ ọ̀rọ.



Digitized by Google

8 Ṣugbọn ọ̀sọnú a ma gbèro ohun ọ̀sọnú;
nipa ohun-ọ̀sọnú ni yio ṣe duro.
9 Dide, ẹnyin obirin ti o wà ni irọra;
gbọ́ ohùn mi, ẹnyin alafara obirin; fetisi
ọ̀rọ mi.
10 Ọpọlọpọ ọjọ, on ọdún, li a o fi ma
wahala nyin, ẹnyin alafara obirin: nitori
ikore kì yio si, kikojọ rẹ̀ kì yio de.
11 Warìri ẹnyin obirin ti o wà ni irọra;
ki wahala ba nyin ẹnyin alafara: ẹ tú aṣọ,
ki ẹ̀ si wà ni ihòho, ki ẹ si dì àmure ẹgbẹ́
nyin.
12 Nwọn o pohùnrere fun ọmú, fun pápa
daradara, ati fun àjara eleso.
13 Ẹgún ọ̀gan on ò̀ṣuṣu yio wá sori ilẹ
awọn enia mi; nitõtọ, si gbogbo ile ayọ̀ ni
ilu alayọ̀.
14 Nitoripe a o kọ̀ ãfin wọnni silẹ; a o
fi ilu ariwo na silẹ; odi ati ile-iṣọ́ ni yio
di ihò titi lai, ayọ̀ fun kẹtẹkẹ́tẹ-igbẹ, pápa-
oko fun ọwọ́-ẹran;
15 Titi a o fi tú Ẹmi jade si wa lara lati
oke wá, ati ti aginju yio fi di ilẹ eleso, ti a
o si kà ilẹ eleso si bi igbo.
16 Nigbana ni idajọ yio ma gbe aginju;
ati ododo ninu ilẹ eleso.
17 Iṣẹ ododo yio si jẹ alafia, ati eso odo-
do yio jẹ idakẹjẹ on ãbo titi lai.
18 Awọn enia mi yio si ma gbe ibugbe
alafia, ati ni ibugbe idaniloju, ati ni ibi
isimi iparọrọ;
19 Ṣugbọn yio rọ̀ yìnyín, nigbati igbó
nṣubu lulẹ; ati ni irẹlẹ a o rẹ̀ ilu na silẹ.
20 Alabukun fun ni ẹnyin ti nfọ́nrugbìn
niha omi gbogbo, ti nrán ẹsẹ malu ati ti
kẹtẹkẹtẹ jade sibẹ.

## ORI 33.

EGBÉ ni fun iwọ abanijẹ, ti a kò si bà ọ
jẹ: ti o nhùwa arekereke, ti a kò si
hùwa arekereke si ọ! nigbati iwọ o dẹkun
ati banijẹ, a o bà ọ jẹ; ati nigbati iwọ bá
fi opin si ihùwa arekereke, nwọn o hùwa
arekereke si ọ.
2 Oluwa, ṣãnu fun wa; awa ti duro dè
ọ: iwọ ma ṣe apá wọn li òrowurọ̀, ani igba-
la wa nigba ipọnju.
3 Li ariwo irọ́kẹ̀kẹ li awọn enia sá, ni
gbigbe ara rẹ soke li a fọ́n awọn orilẹ-ède
ká.
4 A o si ṣà ikogun nyin jọ bi ikojọ awọn
ṣiẹngà: bi isure siwa, isure sẹhìn awọn
ẹlú, li on o sure si wọn.
5 Gbìgbega li Oluwa; nitori on ngbe
ibi giga: on ti fi idajọ ati ododo kún
Sioni.
6 On o si jẹ iduroṣinṣin akoko rẹ̀, iṣura
igbala, ọgbọ́n ati ìmọ; ìbẹru Oluwa ni yio
jẹ iṣura rẹ̀.
7 Kiyesi i, awọn akọni kigbe lode, awọn
ikọ̀ alafia sọkún kikorò.
8 Ọ̀na opopo nla wọnni ṣófo, èro dá, on
ti bà majẹmu jẹ, o ti kẹgàn ilu wọnni, kò
kà ẹnikan si.
9 Ilẹ ngbawẹ̀ o si njoro, oju ntì Leba-
noni o si rọ: Ṣaroni dabi aginju; ati Ba-
ṣani ati Karmeli gbọ̀n eso wọn danù.
10 Oluwa wipe, nisisiyi li emi o dide;
nisisiyi li emi o gbe ara mi soke.
11 Ẹ o loyun iyangbò, ẹ o si bi pòro-
póro; ẽmi nyin, bi iná, yio jẹ nyin run.
12 Awọn enia yio si dabi sisun ẽru, bi
ẹgún ti a ké ni nwọn o jo ninu iná.
13 Ẹ gbọ́, ẹnyin ti o jìna rére, eyi ti mo
ti ṣe; ati ẹnyin ti o sunmọ tosí, ẹ jẹwọ
agbara mi.
14 Ẹru bà awọn ẹlẹṣẹ ni Sioni; ibẹru-
bojo ti mu awọn agabàgebè. Tani ninu
wa ti o le gbe inu ajonirun iná? tani ninu
wa ti yio le gbe inu iná ainipẹkun?
15 Ẹniti nrìn li ododo, ti o si nsọ̀rọ titọ́;
ẹniti o gàn ère ininilara, ti o gbọ̀n ọwọ́ rẹ̀
kuro ni gbigbà abẹtẹlẹ, ti o di eti rẹ̀ ni
gbigbọ́ ti ẹ̀jẹ, ti o si di oju rẹ̀ ni riri ibi.
16 On na yio gbe ibi giga: ile apáta yio
ṣe ibi ãbo rẹ̀: a o fi onjẹ fun u; omi rẹ̀ yio
si daju.
17 Oju rẹ yio ri ọba ninu ẹwà rẹ̀: nwọn
o ma wò ilẹ ti o jinà rére.
18 Aiyà rẹ yio ṣe aṣaro ẹ̀ru nla. Nibo
ni akọwe wà? nibo ni ẹniti nwọ̀n nkan gbe
wà? nibo ni ẹniti o nkà ile-ẹ̀ṣọ wọnni gbe
wà?
19 Iwọ kì yio ri awọn enia ti o muná;
awọn enia ti ọ̀rọ wọn jinlẹ jù eyiti iwọ le
gbọ́, ti ahọn wọn ṣe ololò, ti kò le ye ọ.
20 Wo Sioni, ilu ajọ 'afiyesi wa: oju rẹ
yio ri Jerusalemu ibugbe idakẹjẹ, agọ́ ti a
kì yio tú palẹ mọ; kò si ọkan ninu ẽkàn
rẹ ti a o ṣí ni ipò lai, bẹ̃ni kì yio si ọkan
ninu okùn rẹ̀ ti yio já.
21 Ṣugbọn nibẹ ni Oluwa ogo yio ri fun
wa, bi ibi odò gbigbòro on odò ṣiṣàn: ni-
biti ọkọ̀ alajẹ̀ kì yio kọja, bẹ̃ni ọkọ̀ nlanla
ki yio là a ja.
22 Nitori Oluwa ni onidajọ wa, Oluwa
li olofin wa, Oluwa li ọba wa; on o gbà wa
là.
23 Okùn opó-ọkọ̀ rẹ tú; nwọn kò le dì
opó-ọkọ̀ mu le rere, nwọn kò le ta igbo-
kun: nigbana li a pin ikogun nla; amọ́-
kun ko ikogun.

Digitized by Google

24 Ati awọn ará ibẹ̀ ki yio wipe, Õtù
npa mi: a o dari aiṣedede awọn enia ti
ngbe ibẹ ji wọn.

## ORI 34.

SUNMỌ tosí, ẹnyin orilẹ-ède lati gbọ́, tẹ-
tisilẹ ẹnyin enia, jẹ ki aiye gbọ́, ati
ẹ̀kun rẹ̀; aiye ati ohun gbogbo ti o ti inu
rẹ̀ jade.
2 Nitori ibinu Oluwa mbẹ lara gbogbo
orilẹ-ède, ati irúnu rẹ̀ lori gbogbo ogun
wọn: o ti pa wọn run patapata, o ti fi wọn
fun pipa.
3 Awọn ti a pa ninu wọn li a o si jù
sode, õrùn wọn yio ti inu okú wọn jade,
awọn okenla yio si yọ́ nipa ẹ̀jẹ wọn.
4 Gbogbo awọn ogun ọrun ni yio di yiyọ́,
a o si ká awọn ọrun lọ bi takàda, gbogbo
ogun wọn yio si ṣubu lulẹ, bi ewe ti ibọ́
kuro lara àjara, ati bi bibọ́ eso lara igi
ọ̀pọtọ́.
5 Nitori ti a rẹ́ idà mi li ọrun, kiyesi i,
yio sọkalẹ wá sori Idumea, ati sori awọn
enia egún mi, fun idajọ.
6 Idà Oluwa kun fun ẹ̀jẹ, a mu u sanra
fun ọ̀ra, ati fun ẹ̀jẹ ọdọ-agutan ati ewurẹ,
fun ọrá erẽ àgbo: nitori ti Oluwa ni irubọ
kan ni Bosra, ati ipakupa nla kan ni ilẹ
Idumea.
7 Ati awọn agbanrere yio bá wọn sọkalẹ
wá, ati awọn ẹgbọ̀rọ malu pẹlu awọn akọ
malu; ilẹ wọn li a o fi ẹ̀jẹ rin, a o si fi ọ̀rá
sọ ekuru wọn di ọlọ́ra.
8 Nitori ọjọ ẹsan Oluwa ni, ati ọdun
isanpadà, nitori ọ̀ran Sioni.
9 Odò rẹ̀ li a o si sọ di ọ̀dà, ati ekuru rẹ̀
di imiõrun, ilẹ rẹ̀ yio si di ọ̀dà ti njona.
10 A kì o pa a li oru tabi li ọsan; ẽfin
rẹ̀ yio goke lailai: yio dahoro lati iran de
iran; kò si ẹnikan ti yio là a kọja lai ati
lailai.
11 Ṣugbọn ẹiyẹ ofú ati àkala ni yio ni i;
ati owiwi ati iwò ni yio ma gbe inu rẹ̀: on
o si nà okùn iparun sori rẹ̀, ati okuta ofo.
12 Niti awọn ijoye rẹ̀ ẹnikan kì yio si
nibẹ ti nwọn o pè wá si ijọba, gbogbo awọn
olori rẹ̀ yio si di asan.
13 Ẹgún yio si hù jade ninu ãfin rẹ̀
wọnni, ẹgún ọ̀gan ninu ilú olodi rẹ̀: yio jẹ
ibugbé awọn dragoni, ati agbalá fun awọn
owiwi.
14 Awọn ẹran ijù ati awọn ọ̀wawa ni yio
pade, ati satire kan yio ma kọ si ekeji rẹ̀;
iwin yio ma gbe ibẹ̀ pẹlu, yio si ri ibí isimi
fun ara rẹ̀.
15 Owiwi yio tẹ́ itẹ́ rẹ̀ sibẹ̀, yio yín, yio
si pa, yio si kojọ labẹ ojiji rẹ̀: awọn gú-
nugú yio pejọ sibẹ pẹlu, olukuluku pẹlu
ẹnikeji rẹ̀.
16 Ẹ wá a ninu iwe Oluwa, ẹ si kà a:
ọkan ninu wọnyi kì yio yẹ̀, kò si ọkan ti
yio fẹ́ ekeji rẹ̀ kù: nitori ẹnu mi on li o ti
paṣẹ, ẹmi rẹ̀ li o ti ko wọn jọ.
17 On ti dì ibo fun wọn, ọwọ́ rẹ̀ si fi tita
okùn pin i fun wọn: nwọn o jogun rẹ̀ lai-
lai, lati iran de iran ni nwọn o ma gbe inu
rẹ̀.

## ORI 35.

AGINJU ati ilẹ gbigbẹ yio yọ̀ fun wọn;
ijù yio yọ̀, yio si tanna bi lili.
2 Ni titanna yio tanna; yio si yọ̀ ani
pẹlu ayọ̀ ati orin: ogo Lebanoni li a o fi
fun u, ẹwà Karmeli on Ṣaroni; nwọn o ri
ogo Oluwa, ati ẹwà Ọlọrun wa.
3 Ẹ mu ọwọ́ ailera le, ẹ si mu ẽkun ailera
nokun.
4 Ẹ sọ fun awọn alailaiyà pe, ẹ tujuka,
ẹ má bẹ̀ru: wò o, Ọlọrun nyin o wá ti on
ti ẹsan, Ọlọrun ti on ti igbẹsan; on o wá,
yio si gbà nyin.
5 Nigbana li oju awọn afọju yio là, eti
awọn aditi yio si ṣi.
6 Nigbana li awọn arọ yio fò bi agbọ̀n-
rin, ati ahọn odi yio kọrin: nitori omi
yio tú jade li aginju, ati iṣàn omi ni ijù.
7 Ilẹ yíyan yio si di àbata, ati ilẹ ongbẹ
yio di isun omi; ni ibugbé awọn dragoni,
nibiti olukuluku dubulẹ, ni o jẹ ọgbà fun
ẽsú on iyè.
8 Opopo kan yio si wà nibẹ, ati ọ̀na kan,
a o si ma pè e ni, Ọ̀na iwà-mimọ́; alaimọ́
kì yio kọja nibẹ; nitori on o wà pẹlu wọn:
awọn èro ọ̀na na, bi nwọn tilẹ jẹ ọ̀pe, nwọn
kì yio ṣì i.
9 Kiniun kì yio si nibẹ, bẽni ẹrankọ
buburu kì yio gùn u, a kì yio ri i nibẹ;
ṣugbọn awọn ti a ràpada ni yio ma rin
nibẹ:
10 Awọn ẹni-iràpada Oluwa yio padà,
nwọn o wá si Sioni ti awọn ti orin, ayọ̀
ainipẹkun yio si wà li ori wọn: nwọn o ri
ayọ̀ ati inu didùn gbà, ikãnu on imí-ẹ̀dùn
yio si fò lọ.

## ORI 36.

OSI di igbati o ṣe li ọdun ikẹrinla Hese-
kiah ọba, Sennakaribi ọba Assiria wá
dótì gbogbo ilu olodi Juda, o si kó wọn.
2 Ọba Assiria si rán Rabṣake lati Lakiṣi
lọ si Jerusalemu, ti on ti ogun nla, sọdọ

Digitized by Google

Hesekiah ọba. O si duro lẹba idari omi
abàta oke, li opopo pápa afọṣọ.
3 Nigbana ni Eliakimu ọmọ Hilkia,
olùtọ́ju ile, jade tọ̀ ọ wá, pẹlu Ṣebna akọ-
we, ati Joa ọmọ Asafu, akọwe iranti.
4 Rabṣake si wi fun wọn pe, Ẹ wi fun
Hesekiah nisisiyi, pe, Bayi li ọba nla, ọba
Assiria wi, pe, Igbẹkẹle wo ni eyi ti iwọ
gbe ara le yi?
5 Iwọ wi pe, Mo ni, (ṣugbọn ọ̀rọ ète
lasan ni nwọn) emi ni ìmọ ati agbara fun
ogun jija: njẹ tani iwọ tilẹ gbẹkẹle ti iwọ
fi nṣọ̀tẹ si mi?
6 Wò o, iwọ gbẹkẹle ọpá iyè fifọ́ yi, le
Egipti; eyiti bi ẹnikẹni ba fi ara tì, yio
wọnu ọwọ́ rẹ̀, yio si gún u: bẽni Farao ọba
Egipti ri si gbogbo awọn ti o gbẹkẹle e.
7 Ṣugbọn bi iwọ ba wi fun mi pe, Awa
gbẹkẹle Oluwa Ọlọrun wa: on kọ́ ẹniti
Hesekiah ti mu ibi giga rẹ̀ wọnni, ati pẹpẹ
rẹ̀ wọnni kuro, ti o si wi fun Juda ati
Jerusalemu pe, ẹnyin o ma sìn niwaju
pẹpẹ yi?
8 Njẹ nisisiyi, emi bẹ̀ ọ, mu ohun-iyàn wá
fun oluwa mi ọba Assiria, emi o si fun ọ li
ẹgbã ẹṣin, bi iwọ nipa tirẹ ba le ni enia to
lati gùn wọn.
9 Njẹ iwọ o ti ṣe le yi oju balogun kan
pada ninu awọn ti o rẹhin jù ninu awọn
iranṣẹ oluwa mi, ti iwọ si ngbẹkẹ rẹ le
Egipti fun kẹkẹ́, ati fun ẹlẹṣin?
10 Emi ha dá goke wá nisisiyi lẹhin
Oluwa si ilẹ yi lati pa a run bi? Oluwa wi
fun mi pe, Goke lọ si ilẹ yi, ki o si pa a
run.
11 Nigbana ni Eliakimu ati Ṣebna ati
Joa wi fun Rabṣake pe, Mo bẹ̀ ọ, ba awọn
ọmọ-ọdọ rẹ sọ̀rọ li ède Siria, nitori awa
gbọ́: má si ṣe ba wa sọ̀rọ li ède Ju, li eti
awọn enia ti o wà lori odi.
12 Ṣugbọn Rabṣake wipe, Oluwa mi ha
rán mi si oluwa rẹ lati sọ ọ̀rọ wọnyi? kò ha
ran mi sọdọ awọn ọkọnrin ti o joko lori
odi, ki nwọn ki o le ma jẹ igbẹ́ ara wọn, ki
nwọn si ma mu ìtọ ara wọn pẹlu nyin?
13 Nigbana ni Rabṣake duro, o si fi
ohùn rara kigbe li ède awọn Ju, o si wipe,
Ẹ gbọ́ ọ̀rọ ọba nla, ọba Assiria.
14 Bayi ni ọba na wi, pe, Ẹ máṣe jẹ ki
Hesekiah tán nyin jẹ: nitori on kì o lè gbà
nyin.
15 Ẹ máṣe jẹ ki Hesekiah ki o mu nyin
gbẹkẹle Oluwa, wipe, Ni gbigbà Oluwa yio
gbà wa, a ki o fi ilu yi le ọba Assiria lọwọ.
16 Ẹ máṣe fetisi ti Hesekiah: nitori
bayi li ọba Assiria wi pe, Ẹ fi ẹ̀bun bá mi
rẹ́, ki ẹ si jade tọ̀ mi wá: ki olukuluku
nyin ma jẹ ninu àjara rẹ̀, ati olukuluku
nyin ninu igi ọ̀pọtọ́ rẹ̀, ki olukuluku nyin
si ma mu omi ninu àmu on tikalarẹ̀;
17 Titi emi o fi wá lati mu nyin lọ si ilẹ
kan bi ilẹ ẹnyin tikala nyin, ilẹ ọ̀ka ati ọti-
waini ilẹ onjẹ ati ọ̀gba àjara.
18 Ẹ ṣọra ki Hesekiah ki o má pa nyin
niyè dà wipe, Oluwa yio gbà wa, ọkan
ninu òriṣa awọn orilẹ-ède ha gba ilẹ rẹ̀
lọwọ ọba Assiria ri bi?
19 Nibo li awọn òriṣa Hamati on Arfardi
gbe wà? Nibo li awọn òriṣa Sefarfaimu
wà? nwọn ha si ti gbà Samaria li ọwọ́ mi
bi?
20 Tani ninu gbogbo oriṣa ilẹ wọnyi, ti
o ti gbà ilẹ wọn kuro li ọwọ́ mi, ti Oluwa
yio fi gbà Jerusalemu kuro li ọwọ́ mi?
21 Ṣugbọn nwọn dakẹ, nwọn kò si da a
lohùn ọ̀rọ kan: nitoriti aṣẹ ọba ni, pe, Ẹ
máṣe da a lohùn.
22 Nigbana ni Eliakimu, ọmọ Hilkia, ti
iṣe olutọju ile, ati Ṣebna akọwe, ati Joa,
ọmọ Asafu akọwe iranti, wá sọdọ Hesekiah
ti awọn ti aṣọ wọn ni fifàya, nwọn si sọ ọ̀rọ
Rabṣake fun u.

## ORI 37.

O SI ṣe, nigbati Hesekiah ọba gbọ́, o fà
aṣọ rẹ̀ ya, o si fi aṣọ ọ̀fọ bora, o si lọ
sinu ile Oluwa.
2 O si ran Eliakimu, ti o ṣe olutọju ile,
ati Ṣebna akọwe, ati awọn agba alufa ti
nwọn fi aṣọ ọ̀fọ bora, sọdọ Isaiah woli, ọmọ
Amosi.
3 Nwọn si wi fun u pe, Bayi ni Hese-
kiah wi, Oni jẹ ọjọ wahalà, ati ibawi, ati
ẹgàn: nitori awọn ọmọ de igbà ibí, agbara
kò si si lati bí wọn.
4 Bọya Oluwa Ọlọrun rẹ yio gbọ́ ọ̀rọ
Rabṣake, ẹniti oluwa rẹ̀ ọba Assiria ti rán
lati gàn Ọlọrun alãyè, yio si ba ọ̀rọ ti
Oluwa Ọlọrun rẹ ti gbọ́ wi: nitorina gbe
adura rẹ soke fun awọn iyokù ti o kù.
5 Bẽni awọn iranṣẹ Hesekiah ọba wá
sọdọ Isaiah.
6 Isaiah si wi fun wọn pe, Bayi ni ki ẹ
wi fun oluwa nyin, pe, Bayi ni Oluwa wi,
Máṣe bẹ̀ru ọ̀rọ ti iwọ ti gbọ́, nipa eyiti
awọn iranṣẹ ọba Assiria ti fi sọ̀rọ buburu
si mi.
7 Wò o, emi o fi ẽmi kan sinu rẹ̀, on o
si gbọ́ iró kan, yio si pada si ilu on tika-
larẹ̀; emi o si mu ki o ti ipa idà ṣubu ni
ilẹ on tikalarẹ̀.
8 Bẽni Rabṣake padà, o si ba ọba Assiria

Digitized by Google

mba Libna jagun: nitori ti o ti gbọ́ pe o
ti kuro ni Lakiṣi.
9 O si gbọ́ a nwi niti Tirhaka ọba
Etiopia, pe, O mbọ̀ wá ba iwọ jagun.
Nigbati o si gbọ́, o rán awọn ikọ̀ lọ sọdọ
Hesekiah, wipe,
10 Bayi ni ki ẹ wi fun Hesekiah ọba
Juda, pe, Má jẹ ki Ọlọrun rẹ, ẹniti iwọ
gbẹkẹle, ki o tàn ọ jẹ, wipe, A kì yio fi
Jerusalemu le ọba Assiria lọwọ.
11 Kiyesi i, iwọ ti gbọ́ ohun ti awọn ọba
Assiria ti ṣe si ilẹ gbogbo bi nwọn ti pa
wọn run patapata: a o si gbà iwọ bi?
12 Oriṣa awọn orilẹ-ède ha gbà awọn ti
awọn baba mi ti parun bi? bi Gosani, ati
Harani ati Resefu, ati awọn ọmọ Edeni ti
nwọn ti wà ni Telassari?
13 Nibo ni ọba Hamati wà, ati ọba
Arfadi, ati ọba ilu Sefarfaimu, Hena, ati
Ifa?
14 Hesekiah si gbà iwe na lọwọ awọn
ikọ̀, o si kà a: Hesekiah si gòke lọ si ile
Oluwa, o si tẹ́ ẹ siwaju Oluwa.
15 Hesekiah si gbadura si Oluwa, wipe,
16 Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Isra-
eli, ti ngbe ãrin awọn kerubu, iwọ li
Ọlọrun, ani iwọ nikan, ninu gbogbo ijọba
aiye: iwọ li o dá ọrun on aiye.
17 Dẹti rẹ silẹ, Oluwa, ki o si gbọ́; ṣi
oju rẹ, Oluwa, ki o si wò: si gbọ́ gbogbo
ọ̀rọ Senakeribu, ti o ranṣẹ lati kẹgàn
Ọlọrun alãyè.
18 Lõtọ ni, Oluwa, awọn ọba Assiria ti
sọ gbogbo orilẹ-ède di ahoro, ati ilẹ wọn,
19 Nwọn si ti sọ awọn òriṣa wọn sinu
iná: nitori ọlọrun ki nwọn iṣe, ṣugbọn iṣẹ
ọwọ́ enia ni, igi ati òkuta: nitorina ni nwọn
ṣe pá wọn run.
20 Njẹ nisisiyi, Oluwa Ọlọrun wa, gbà
wa lọwọ rẹ̀, ki gbogbo ijọba aiye le mọ̀ pe
iwọ ni Oluwa, ani iwọ nikanṣoṣo.
21 Nigbana ni Isaiah ọmọ Amosi ranṣẹ
si Hesekiah, wipe, Bayi ni Oluwa Ọlọrun
Israeli wi, niwọ̀n bi iwọ ti gbadura si mi niti
Sennakeribu ọba Assiria:
22 Eyi ni ọ̀rọ ti Oluwa ti sọ niti rẹ̀:
Wundia, ọmọbirin Sioni, ti kẹgàn rẹ, o si
ti fi ọ rẹrin ẹlẹyà; ọmọbirin Jerusalemu ti
mì ori rẹ̀ si ọ.
23 Tani iwọ kẹgàn ti o si sọ̀rọ buburu
si? tani iwọ si gbe oju rẹ ga si, ti o si gbe
oju rẹ soke gangan? si Ẹni-Mimọ́ Israeli ni.
24 Nipasẹ awọn iranṣẹ rẹ li o ti kẹgàn
Oluwa, ti o si ti wipe, Ni ọ̀pọlọpọ kẹkẹ́ mi,
emi ti goke wá si oke awọn oke giga, si
ẹba Lebanoni; emi o si ke igi kedari rẹ̀
giga lulẹ, ati ãyò igi firi rẹ̀, emi o si wá si
ẹnu agbègbe rẹ̀, ati si igbó Karmeli rẹ̀.
25 Emi ti wà kanga, mo si ti mu omi;
atẹlẹsẹ mi ni mo si ti fi mu gbogbo odò ibi
ihamọ gbẹ.
26 Iwọ kò ti gbọ́ ri pe, lai emi li o ti
ṣe e, ati pe emi li o ti dá a nigba atijọ?
nisisiyi mo mu u ṣẹ, ki iwọ ki o sọ ilu-nla
olodi dahoro di okiti iparun.
27 Nitorina ni awọn olugbé wọn fi ṣe
alainipa, aiya fò wọn, nwọn si dãmu:
nwọn dabi koriko igbẹ, ati bi ewebẹ̀ tutù,
bi koriko lori oté ile, ati bi ọkà ti igbẹ ki
o to dàgba soke.
28 Ṣugbọn mo mọ̀ ibugbe rẹ, ijadelọ rẹ,
ati iwọle rẹ, ati irúnu rẹ si mi.
29 Nitori irúnu rẹ si mi, ati igberaga rẹ,
ti goke wá si eti mi, nitorina ni emi o ṣe
fi ìwọ mi kọ́ ọ ni imú, ati ijanu mi si ète
rẹ, emi o si mu ọ pada li ọ̀na ti o ba wá.
30 Eyi ni o si jẹ àmi fun ọ, Ẹ jẹ ilalẹ̀hu
li ọdun yi; ati li ọdun keji eyiti o sọ jade
ninu ọkanna: ati li ọdun kẹta ẹ fọnrugbìn,
ki ẹ si kore, ki ẹ si gbìn ọgba àjara, ki
ẹ si jẹ eso wọn.
31 Ati iyokù ti o sala ninu ile Juda yio
tun fi gbòngbo mulẹ nisalẹ, yio si so eso
loke:
32 Nitori lati Jerusalemu ni iyokù yio
jade lọ, ati awọn ti o sala lati oke Sioni
wá: itara Oluwa awọn ọmọ-ogun yio ṣe eyi.
33 Nitorina bayi ni Oluwa wi niti ọba
Assiria, on kì yio wá si ilu yi, bẽni kì yio
ta ọ̀fa kan sibẹ, kì yio si mu asà wá
siwaju rẹ̀, bẽni kì yio wà odi tì i.
34 Li ọ̀na ti o ba wá, li ọkanna ni yio
bá padà, kò si ni wá si ilu yi, li Oluwa wi.
35 Nitori emi o dãbo bò ilu yi lati gbà
a nitoriti emi tikala mi, ati nitoriti Dafidi
iranṣẹ mi.
36 Angeli Oluwa si jade lọ, o si pa ọkẹ́
mẹsan o le ẹgbẹ̃dọgbọn ni budo awọn ara
Assiria; nigbati nwọn si dide lowurọ kùtu-
kutu, kiyesi i, gbogbo wọn jẹ okú.
37 Bẽni Sennakeribu ọba Assiria mu
ọ̀na rẹ̀ pọn, o si lọ, o si padà, o si ngbe
Ninefe.
38 O si di igbati o ṣe, bi o ti ntẹriba ni
ile Nisroki oriṣa rẹ̀, ni Adrammeleki ati
Ṣaresari awọn ọmọ rẹ̀ fi idà pa a; nwọn
si salà si ilẹ Armenia: Esarhaddoni ọmọ
rẹ̀ si jọba ni ipò rẹ̀.

## ORI 38.

LI ọjọ wọnni Hesekiah ṣaisàn de oju ikú.
Woli Isaiah ọmọ Amosi si wá sọdọ rẹ̀,

Digitized by Google

o si wi fun u pe, Bayi ni Oluwa wi, Palẹ
ile rẹ mọ́: nitori iwọ o kú, o ki yio si yè.
2 Nigbana ni Hesekiah yi oju rẹ̀ si ogiri,
o si gbadura si Oluwa.
3 O si wipe, Nisisiyi, Oluwa, mo bẹ̀ ọ́,
ranti bi mo ti rìn niwaju rẹ li otitọ ati
pẹlu aiya pipé, ati bi mo si ti ṣe eyiti o
dara li oju rẹ. Hesekiah si 'sọkún pẹrẹ̀-
pẹrẹ̀.
4 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ Isaiah wá, wipe,
5 Lọ, si wi fun Hesekiah pe, Bayi ni
Oluwa, Ọlọrun Dafidi baba rẹ wi, mo ti
gbọ́ adura rẹ, mo ti ri omije rẹ: kiyesi i
emi o fi ọdun mẽdogun kún ọjọ rẹ.
6 Emi o si gbà ọ ati ilu yi lọwọ ọba
Assiria: emi o si dãbò bò ilu yi.
7 Eyi yio si jẹ àmi fun ọ lati ọdọ Oluwa
wá, pe, Oluwa yio ṣe nkan yi ti o ti sọ;
8 Kiyesi i, emi o tún mu ìwọn òjiji ti
o ti sọkalẹ lara agogo-õrùn Ahasi pada ni
ìwọn mẹwa. Bẽni õrùn pada ni ìwọn mẹwa
ninu ìwọn ti o ti sọkalẹ.
9 Iwe Hesekiah ọba Juda, nigbati o fi
ṣaisàn, ti o si sàn ninu aisàn rẹ̀:
10 Mo ni, ni ìke-kuro ọjọ mi, emi o lọ
si ẹnu-ọnà isà-okú; a dù mi ni iyokù ọdun
mi.
11 Mo ni, emi kì yio ri Oluwa, ani
Oluwa, ni ilẹ alãyè: emi kì yio ri enia
mọ lãrin awọn ti ngbé ibi idakẹ.
12 Ọjọ ori mi lọ, a si ṣi i kuro lọdọ mi bi
àgọ olùṣọ agutan; mo ti ké ẹmi mi kuro
bi awunṣọ: yio ké mi kuro bi fọ́nran-òwu
tirin: lati òsan de oru ni iwọ o mu mi de
òpin mi.
13 Mo ṣirò titi di òwurọ, pe, bi kiniun,
bẽni yio fọ́ gbogbo egungun mi; lati ọ̀san
de oru ni iwọ o mu mi de òpin mi.
14 Bi akọ̀ tabi alapandẹ̀dẹ, bẽni mo
dún; mo kãnu bi oriri: ãrẹ̀ mu oju mi
fun iwòke: Oluwa, ara nni mi: ṣe oni-
gbọwọ mi.
15 Kili emi o wi? o ti sọ fun mi, on
tikalarẹ̀ si ti ṣe e: emi o ma lọ jẹjẹ fun
gbogbo ọdun mi ni kikorò ọkàn mi.
16 Oluwa, nipa nkán wọnyi li enia ima
wà, ati ni gbogbo nkan wọnyi ni iye ẹmi
mi: bẽni iwọ o mu mi lara dá, iwọ o si
mu mi yè.
17 Kiyesi i, mo ti ni ikorò nla nipò
alafia: ṣugbọn iwọ ti fẹ́ ọkàn mi lati ihò
idibàjẹ wá: nitori iwọ ti gbe gbogbo ẹ̀ṣẹ
mi si ẹ̀hin rẹ.
18 Nitori iboji kò le yìn ọ, ikú kò le
fiyìn fun ọ: awọn ti o sọkalẹ lọ sinu ihò
kò le ni irèti otitọ rẹ.
19 Alãyè, alãyè, on ni yio yìn ọ, bi mo
ti nṣe loni yi: baba yio fi otitọ rẹ hàn fun
awọn ọmọ.
20 Oluwa mura tan lati gbà mi: ni-
torina a o kọ orin mi lara dùrù olokùn, ni
gbogbo ọjọ aiye wa ni ile Oluwa.
21 Nitori Isaiah ti wipe, Ki nwọn mu
ìṣu ọ̀pọtọ́, ki a si fi ṣán õwo na, yio si sàn.
22 Hesekiah pẹlu ti wipe, Kili àmi na
pe emi o goke lọ si ile Oluwa?

## ORI 39.

LI akoko na ni Merodaki-baladani, ọmọ
Baladani, ọba Babiloni, rán iwe ati
ọrẹ si Hesekiah: nitori o ti gbọ́ pe o ti
ṣaisàn, o si ti sàn.
2 Inu Hesekiah si dùn si wọn, o si fi
ile iṣura hàn wọn, fadaka, ati wura, ati
nkan olõrun didùn, ati ikunra iyebiye, ati
ile gbogbo ìhamọra rẹ̀, ati ohun gbogbo ti
a ri ninu iṣura rẹ̀: kò si si nkankan ti
Hesekiah kò fi hàn wọn ninu ile rẹ̀, tabi
ni ijọba rẹ̀.
3 Nigbana ni woli Isaiah wá sọdọ Hese-
kiah ọba, o si wi fun u pe, Kini awọn
ọkọnrin wọnyi wi? ati lati ibo ni nwọn ti
wá sọdọ rẹ? Hesekiah si wi pe, Lati ilẹ
jijin ni nwọn ti wá sọdọ mi, ani lati
Babiloni.
4 O si wipe, Kini nwọn ri ni ile rẹ?
Hesekiah si dahùn pe, Ohun gbogbo ti o
wà ni ile mi ni nwọn ti ri: kò si nkankan
ti emi kò fi hàn wọn ninu iṣura mi.
5 Nigbana ni Isaiah wi fun Hesekiah
pe, Gbọ́ ọ̀rọ Oluwa awọn ọmọ-ogun:
6 Kiyesi i, ọjọ na dé, ti a o kó ohun
gbogbo ti o wà ni ile rẹ, ati ohun ti awọn
baba rẹ ti kojọ titi di oni, lọ si Babiloni:
kò si nkankan ti yio kù, li Oluwa wi.
7 Ati ninu awọn ọmọ rẹ ọkọnrin ti yio
ti inu rẹ jade, ti iwọ o bi, ni nwọn o kó
lọ: nwọn o si jẹ́ iwẹ̀fa ni ãfin ọba Babiloni.
8 Nigbana ni Hesekiah wi fun Isaiah
pe, Rere ni ọ̀rọ Oluwa ti iwọ ti sọ. O
si wi pẹlu pe, Alafia ati otitọ́ yio sa wà li
ọjọ mi.

## ORI 40.

ẸTÙ enia mi ninu, ẹ tù wọn ninu, ni
Ọlọrun nyin wi.
2 Ẹ sọ ọ̀rọ ìtunu fun Jerusalemu, ki ẹ
si ké si i pe, ogun jijà rẹ tán, pe, a dari
aiṣedẽde rẹ ji: nitoripe o ti gbà nigba meji
lati ọwọ́ Oluwa wá fun ẹ̀ṣẹ rẹ̀ gbogbo.

Digitized by Google

3 Ohùn ẹniti nkigbe ni ijù, ẹ tún ọ̀na Oluwa ṣe, ṣe opópo titọ́ ni aginjù fun Ọlọrun wa.

4 Gbogbo afonifoji ni a o gbe soke, gbogbo òkenla ati òke kékèké ni a o si rẹ̀ silẹ: wiwọ́ ni a o si ṣe ni titọ́, ati ọ̀na pàlapala ni a o sọ di titẹ́ju:

5 A o si fi ogo Oluwa hàn, gbogbo ẹran-ara ni yio jùmọ ri i: nitori ẹnu Oluwa li o sọ ọ.

6 Ohùn na wipe, Kigbe. On si wipe, Igbe kini emi o ke? Gbogbo ẹran-ara ni koriko, gbogbo ogo rẹ̀ si dabi ìtana igbẹ́:

7 Koriko nrọ, ìtana eweko nrẹ̀: nitoripe ẹmi Oluwa ti fẹ lù u: dajudaju koriko ni enia.

8 Koriko nrọ, ìtana nrẹ̀: ṣugbọn ọ̀rọ Ọlọrun wa yio duro lailai.

9 Iwọ onihin-rere Sioni, gùn òke giga lọ: Iwọ onihin-rere Jerusalemu, gbé ohùn rẹ soke pẹlu agbara; gbé e soke, má bẹ̀ru; wi fun awọn ilu Juda pe, Ẹ wò Ọlọrun nyin:

10 Kiyesi i, Oluwa Jehofah yio wá ninu agbara, apá rẹ̀ yio ṣe akoso fun u: kiyesi i, ère rẹ̀ wà pẹlu rẹ̀, ẹ̀san rẹ̀ si mbẹ niwaju rẹ̀.

11 On o bọ́ ọwọ-ẹran rẹ̀ bi oluṣọ-agùtan: yio si fi apá rẹ̀ ko awọn ọdọ-agùtan, yio si ko wọn si aiya rẹ̀, yio rọra dà awọn ti o loyun.

12 Tali o ti wọ̀n omi ni kòto-ọwọ́ rẹ̀, ti o si ti fi ika wọ̀n ọrun, ti o si ti kó erùpẹ aiye jọ sinu òṣuwọn, ti o si fi ìwọn wọ̀n awọn oke-nla, ati awọn oke kékèké ninu òṣuwọn?

13 Tali o ti tọ́ Ẹmi Oluwa, tabi ti iṣe igbimọ̀ rẹ̀ ti o kọ́ ọ?

14 Tali o mbá gbìmọ, tali o si kọ́ ọ lẹkọ́, ti o si kọ́ ọ ni ọ̀na idajọ, ti o si kọ́ ọ ni ìmọ, ti o si fi ọ̀na oye hàn a?

15 Kiyesi i, awọn orilẹ-ède dabi iró kan ninu omi ladugbo, a si kà wọn bi ekuru kiun ninu ìwọn: kiyesi i, o nmu awọn erekùṣu bi ohun diẹ kiun.

16 Lebanoni kò si tó fi joná, bẽni awọn ẹranko ibẹ kò to lati fi rubọ sisun.

17 Gbogbo orilẹ-ède li o dabi ofo niwaju rẹ̀; a si kà wọn si fun u bi ohun ti o rẹ̀hin jù ofo ati asan lọ.

18 Tali ẹnyin o ha fi Ọlọrun we? tabi awòran kini ẹnyin o fi ṣe akàwe rẹ̀?

19 Oniṣọ̀na ngbẹ́ ère, alagbẹdẹ wura si nfi wura bò o, o si ndà ẹ̀wọn fadakà.

20 Ẹniti o talakà tobẹ̃ ti kò fi ni ohun ọrẹ, yàn igi ti kì yio rà; o nwá ọlọgbọn oniṣọ̀na fun ara rẹ̀ lati gbẹ́ ère gbigbẹ́ ti a ki yio ṣi nipò.

21 Ẹnyin kò ti mọ̀? ẹnyin kò ti gbọ́? a kò ti sọ fun nyin li atètekọṣe? kò iti yé nyin lati ipilẹṣẹ aiye wá?

22 On ni ẹniti o joko lori òbíri aiye, gbogbo awọn ti ngbe ibẹ si dabi ẹlẹngà; ẹniti o ta ọrun bi ohun tita, ti o si nà wọn bi àgọ lati gbe.

23 Ẹniti o nsọ awọn ọmọ-alade di ofo; o ṣe awọn onidajọ aiye bi asan.

24 Nitõtọ, a kì yio gbìn wọn; nitõtọ, a kì yio sú wọn: nitõtọ igi wọn kì yio fi gbòngbo mulẹ: on o si fẹ́ lù wọn pẹlu, nwọn o si rọ, ãja yio si mu wọn lọ bi akekù koriko.

25 Njẹ tani ẹnyin o ha fi mi we, tabi tali emi o ba dọgbà? ni Ẹni-Mimọ wi.

26 Gbe oju nyin soke sibi giga, ki ẹ si wò, tali o dá nkan wọnyi, ti nmu ogun wọn jade wá ni iye: o npè gbogbo wọn li orukọ nipa titobi ipá rẹ̀, nitoripe on le ni ipá; kò si ọkan ti o kù.

27 Ẽṣe ti iwọ fi nwi, Iwọ Jakobu, ti iwọ si nsọ, Iwọ Israeli pe, Ọ̀na mi pamọ kuro lọdọ Oluwa, idajọ mi si rekọja kuro lọdọ Ọlọrun mi?

28 Iwọ kò ti imọ̀? iwọ kò ti igbọ́, pe, Ọlọrun aiyeraiye, Oluwa, Ẹlẹda gbogbo ipẹkun aiye, kì iṣãrẹ̀, bẽni ãrẹ̀ kì imu u? kò si awari oye rẹ̀.

29 O nfi agbara fun alãrẹ̀; o si fi agbara kún awọn ti kò ni ipá.

30 Ani ãrẹ̀ yio mu awọn ọdọmọde, yio si rẹ̀ wọn, ati awọn ọdọmọkọnrin yio tilẹ ṣubu patapata:

31 Ṣugbọn awọn ti o ba duro de Oluwa yio tun agbara wọn ṣe; nwọn o fi iyẹ́ gùn oke bi idì; nwọn o sare, kì yio si rẹ̀ wọn; nwọn o rìn, ãrẹ̀ kì yio si mu wọn.

## ORI 41.

DAKẸ niwaju mi, Ẹnyin erekùṣu; si jẹ ki awọn enia tún agbara wọn ṣe: jẹ ki wọn sunmọ tosí; nigbana ni ki wọn sọ̀rọ: jẹ ki a jumọ sunmọ tosí fun idajọ.

2 Tali o gbe olododo dide lati gabasi wa, ti o pè e si ẹsẹ rẹ̀, ti o fi awọn orilẹ-ède fun u niwaju rẹ̀, ti o si fi ṣe akoso awọn ọba? o fi wọn fun idà rẹ̀ bi ekuru, ati bi akekù iyàngbo fun ọrun rẹ̀.

3 O lepa wọn, o si kọja li alafia; nipa ọ̀na ti kò ti fi ẹsẹ rẹ̀ tẹ̀ ri.

4 Tali o ti dá a ti o si ti ṣe e, ti o npè awọn iran lati ipilẹṣẹ̀ wá? Emi Oluwa ni; ẹni-ikini, ati pẹlu ẹni-ikẹhìn; Emi na ni.

Digitized by Google

5 Awọn erekùṣu ri i, nwọn si bẹ̀ru ; aiya
nfò awọn opin aiye ; nwọn sunmọ tosí,
nwọn si wá.
6 Olukuluku ràn aladugbo rẹ̀ lọwọ ; o si
wi fun arakọnrin rẹ̀ pe, Ẹ mu ara le.
7 Bẹ̃ni gbẹnàgbẹnà ngbà alagbẹdẹ wura
niyànju, ati ẹniti nfi ọmọ-owú dán a, ngbà
ẹniti nlù ògún niyànju ; wipe, o ṣetan fun
mimọlù : o si fi iṣo kàn a mọra ki o má le
ṣi.
8 Ṣugbọn iwọ, Israeli, ni iranṣẹ mi,
Jakobu ẹniti mo ti yàn, iru-ọmọ Abrahamu
ọrẹ mi.
9 Ẹniti mo ti mu lati opin aiye wá, ti
mo ti pè ọ lati ọdọ awọn olori enia ibẹ, ti
mo si wi fun ọ pe, Iwọ ni iranṣẹ mi ; mo ti
yàn ọ, emi kò si ni ta ọ nù,
10 Iwọ má bẹ̀ru ; nitori mo wà pẹlu rẹ ;
má foyà ; nitori emi ni Ọlọrun rẹ : emi o
fun ọ ni okun ; nitõtọ, emi o ràn ọ lọwọ ;
nitõtọ, emi o fi ọwọ́ ọ̀tun ododo mi gbe ọ
sokè.
11 Kiyesi i, gbogbo awọn ti o binu si ọ
ni oju o tì, nwọn o si dãmu : nwọn o dabi
asan ; awọn ti o si mba ọ jà yio ṣegbe.
12 Iwọ o wá wọn, iwọ kì yio si rí wọn,
ani awọn ti o ba ọ jà : awọn ti o mba ọ
jagun yio dabi asan, ati bi ohun ti kò si.
13 Nitori emi Oluwa Ọlọrun rẹ yio dí
ọwọ́ ọ̀tun rẹ mu, emi o wi fun ọ pe, Má
bẹ̀ru ; emi o ràn ọ lọwọ.
14 Má bẹ̀ru, iwọ Jakobu kòkoro, ati
ẹnyin ọkọnrin Israeli ; emi o ràn ọ lọwọ,
bẹ̃ni Oluwa ati Oluràpada rẹ wi, Ẹni-
mimọ́ Israeli.
15 Kiyesi i, emi ti ṣe ọ bi ohun-èlo
ipakà mimú titun ti o ni ehín ; iwọ o tẹ̀
awọn òke-nla, iwọ o si gún wọn kunná,
iwọ o si sọ awọn oke kékèké di iyàngbo.
16 Iwọ o fẹ́ wọn, ẹfũfu yio si fẹ́ wọn lọ,
ãjà yio si tú wọn ká : iwọ o si yọ̀ ninu
Oluwa, iwọ o si ṣogo ninu Ẹni-Mimọ
Israeli.
17 Nigbati talakà ati alaini nwá omi, ti
kò si si, ti ahọn wọn si gbẹ fun ongbẹ, emi
Oluwa yio gbọ́ ti wọn, emi Ọlọrun Israeli
ki yio kọ̀ wọn silẹ.
18 Emi o ṣi odò nibi giga, ati orisún
lãrin afonifoji : emi o sọ aginjù di abàta
omi, ati ilẹ gbigbẹ di orisun omi.
19 Emi o fi igi kedari si aginjù, ati igi
ṣita, ati mirtili, ati igi oróro ; emi o gbìn
igi firi ati igi pine ati igi boksi pọ̀ ni
aginjù.
20 Ki nwọn ki o le ri, ki nwọn ki o si
mọ̀, ki nwọn si gbèro, ki o si le yé won pọ̀,
pe, ọwọ́ Oluwa li o ti ṣe eyi, ati pe Ẹni-Mimọ
Israeli ni o ti dá a.
21 Mú ẹjọ nyin wá, ni Oluwa wi ; mú
ọràn dajudaju nyin jade wá, ni ọba Jakobu
wi.
22 Jẹ ki wọn mú wọn jade wá, ki nwọn
si fi ohun ti yio ṣe hàn ni : jẹ ki nwọn fi
ohun iṣãju hàn, bi nwọn ti jẹ, ki awa ki o
lè rò wọn, ki a si mọ̀ igbẹ̀hin wọn ; tabi ki
nwọn sọ ohun wọnni ti mbọ̀ fun wa.
23 Fi ohun ti mbọ̀ lẹhìn eyi hàn, ki awa
ki o le mọ̀ pe ọlọrun ni nyin : nitõtọ, ẹ ṣe
rere, tabi ẹ ṣe buburu, ki ẹru le bà wa, ki a
le jumọ ri i.
24 Kiyesi i, lati nkan asan ni nyin, iṣẹ
nyin si jẹ asan : irira ni ẹniti o yàn nyin.
25 Emi ti gbé ẹnikan dide lati ariwa,
on o si wá : lati ilà-õrùn ni yio ti ké pe
orukọ mi : yio si wá sori awọn ọmọ-alade
bi sori àmọ, ati bi alamọ̀ ti itẹ̀ erupẹ.
26 Tani o ti fi hàn lati ipilẹ̀ṣẹ, ki awa
ki o le mọ̀ ? ati nigba iṣãju, ki a le wi pe,
Olododo ni on ? nitõtọ, kò si ẹnikan ti o fi
hàn, nitõtọ, kò si ẹnikan ti o sọ ọ, nitõtọ,
kò si ẹnikan ti o gbọ́ ọ̀rọ nyin.
27 Ẹni-ikini o wi fun Sioni pe, Wò o, on
na nĩ : emi o fi ẹnikan ti o mú ihìn-rere
wá fun Jerusalemu.
28 Nitori mo wò, kò si si ẹnikan ; ani
ninu wọn, kò si si olugbimọ̀ kan, nigbati
mo bere lọwọ wọn, kò si ẹniti o le dahùn
ọ̀rọ kan.
29 Kiyesi i, asan ni gbogbo wọn ; asan
ni iṣẹ wọn ; ẹfũfu ati rudurudu ni ere didà
wọn.

## ORI 42.

WÒ iranṣẹ mi, ẹniti mo gbéro : ayànfẹ
mi, ẹniti inu mi dùn si ; mo ti fi ẹmi
mi fun u : on o mu idajọ wá fun awọn
keferi.
2 On kì yio kigbé, bẹ̃ni kì yio gbé ohùn
soke, bẹ̃ni kì yio jẹ ki a gbọ́ ohùn rẹ̀ ni
igboro.
3 Iyè fifọ́ ni on ki yio ṣẹ, owú ti nrú ẽfin
ni on kì yio pa : yio mu idajọ wá si otitọ.
4 Ãrẹ̀ kì yio mú u, a kì yio si daiyà fò
o, titi yio fi gbé idajọ kalẹ li aiye : awọn
erekùṣu yio duro de ofin rẹ̀.
5 Bayi ni Ọlọrun Oluwa wi, ẹniti o dá
ọrun, ti o si nà wọn jade ; eniti o tẹ̀ aiye,
ati ohun ti o ti inu rẹ̀ wá ; ẹniti o fi ẽmi
fun awọn enia lori rẹ̀, ati ẹmi fun awọn ti
o nrin ninu rẹ̀ :
6 Emi Oluwa li o ti pè ọ ninu ododo,
emi o si di ọwọ́ rẹ mu, emi o si pa ọ mọ,

Digitized by Google

emi o si fi ọ ṣe majẹmu awọn enia, imọlẹ
awọn keferi.
7 Lati là oju awọn afọju, lati mu awọn
ondè kuro ninu tubu, ati awọn ti o joko li
okùnkun kuro ni ile tubu.
8 Emi li Oluwa: eyi ni orukọ mi: ogo
mi li emi kì yio fi fun ẹlòmiran, bẹ̃ni emi kì
yio fi iyìn mi fun ere gbigbẹ́.
9 Kiyesi i, nkan iṣãju ṣẹ, nkan titun ni
emi si nsọ: ki nwọn to hù, mo mu nyin
gbọ́ wọn.
10 Ẹ kọ orin titun si Oluwa, iyìn rẹ̀ lati
opin aiye, ẹnyin ti nsọkalẹ lọ si okun, ati
ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀: erekùṣu, ati
awọn ti ngbè inu wọn.
11 Jẹ ki aginjù ati ilu-nla ibẹ gbé ohùn
wọn soke, iletò wọnni ti Kedari ngbé: jẹ ki
awọn ti ngbé apáta kọrin, jẹ ki wọn hó
lati ori oke-nla wá.
12 Jẹ ki wọn fi ogo fun Oluwa, ki wọn
si wi iyìn rẹ̀ ninu erekùṣu.
13 Oluwa yio jade bi ọkọnrin alagbara,
yio rú owú soke bi ologun: yio kigbé, nitõ-
tọ, yio ké ramuramu; yio bori awọn ọta rẹ̀.
14 Lailai ni mo ti dakẹ́: mo ti gbe jẹ,
mo ti pa ara mi mọra; nisisiyi emi o ké bi
obirin ti nrọbi; emi o parun, emi o si gbé
mì lẹrinkanna.
15 Emi o sọ oke-nla ati òke-kékèké di
ofo, emi o si mú gbogbo ewebẹ̀ wọn gbẹ:
emi o sọ odò ṣiṣàn di iyangbẹ́ ilẹ, emi o si
mú abàta gbẹ.
16 Emi o si mu awọn afọju bá ọ̀na ti
nwọn kò mọ̀ wá; emi o tọ́ wọn ninu ipa ti
wọn kò ti mọ̀; emi o sọ okùnkun di imọlẹ
niwaju wọn, ati ohun wiwọ́ di titọ́. Nkan
wọnyi li emi o ṣe fun wọn, emi kì yio si kọ̀
wọn silẹ.
17 A o dá awọn ti o gbẹkẹle ere gbigbẹ́
padà, a o doju tì wọn gidigidi, awọn ti
nwi fun ere didà pe, Ẹnyin ni ọlọrun wa.
18 Gbọ́, ẹnyin aditi; ki ẹ si wò, ẹnyin
afọju ki ẹnyin ki o le ri i.
19 Tani afọju, bikoṣe iranṣẹ mi? tabi
aditi, bi ikọ̀ mi ti mo rán? tani afọju bi
ẹni pipé? ti o si fọju bi iranṣẹ Oluwa?
20 Ni riri nkan pupọ, ṣugbọn iwọ kò
kiyesi i; ni ṣiṣi eti, ṣugbọn on ko gbọ́.
21 Inu Oluwa dùn gidigidi nitori ododo
rẹ̀; yio gbe ofin ga, yio si sọ ọ di ọlọ́lá.
22 Ṣugbọn enia ti a jà lole ti a si ko li
ẹrù ni eyi: gbogbo wọn li a dẹkùn mu
ninu ihò, a fi wọn pamọ ninu tubu: a fi
wọn fun ikogun, ẹnikan ko si gbà wọn; a
fi wọn fun ikogun, ẹnikan ko si wipe, Mu
u pada.
23 Tani ninu nyin ti o fi eti si eyi? ti o
dẹti silẹ, ti yio si gbọ́ eyi ti mbọ̀ lẹhin?
24 Tani fi Jakobu fun ikogun, ti o si fi
Israeli fun ole? Oluwa ha kọ́, ẹniti a ti
dẹṣẹ si? nitori nwọn kò fẹ rìn li ọ̀na rẹ̀,
bẹ̃ni nwọn ko gbọ́ ti ofin rẹ̀.
25 Nitorina ni o ṣe dà irúnu ibinu rẹ̀ si i
lori, ati agbara ogun: o si ti tẹ̀ iná bọ̀ ọ
yika, ṣugbọn on kò mọ̀; o si jo o, ṣugbọn
on kò kà a si.

## ORI 43.

ṢUGBỌN nisisiyi bayi ni Oluwa wi, ẹniti
o dá ọ, Jakobu, ati ẹniti o mọ ọ, Is-
raeli, Má bẹru: nitori mo ti rà ọ pada, mo
ti pè ọ li orukọ rẹ, ti emi ni iwọ.
2 Nigbati iwọ ba nlà omi kọja, emi o
pẹlu rẹ; ati lãrin odò, nwọn kì yio bò ọ
mọlẹ: nigbati iwọ ba nrìn ninu iná, ki yio
jo ọ, bẹ̃ni ọwọ́-iná ki yio ràn ọ.
3 Nitori emi li Oluwa Ọlọrun rẹ, Ẹni-
Mimọ Israeli, Olugbala rẹ: mo fi Egipti ṣe
irapada rẹ, mo si fi Etiopia ati Seba fun ọ.
4 Niwọn bi iwọ ti ṣe iyebiye to loju mi,
ti iwọ ṣe ọlọla, emi si ti fẹ ọ: nitorina emi
o fi enia rọpò rẹ, ati enia dipo ẹmi rẹ.
5 Má bẹ̀ru: nitọri emi wà pẹlu rẹ; emi
o mu iru-ọmọ rẹ lati gabasi wá, emi o si ṣà
ọ jọ lati yama wá.
6 Emi o wi fun ariwa pe, Da silẹ; ati
fun gusun pe, Máṣe da duro; mu awọn
ọmọ mi ọkọnrin lati okere wá, ati awọn
ọmọ mi obirin lati opin ilẹ wá.
7 Olukuluku ẹniti a npè li orukọ mi:
nitori mo ti dá a fun ogo mi, mo ti mọ ọ,
ani, mo ti ṣe e pé.
8 Mu awọn afọju enia ti o li oju jade wá,
ati awọn aditi ti o li eti.
9 Jẹ ki gbogbo awọn orilẹ-ède ṣa ara
wọn jọ pọ̀, ki awọn enia pejọ; tani ninu
wọn ti o le sọ eyi, ti o si le fi ohun atijọ
han ni? jẹ ki wọn mu awọn ẹlẹri wọn jade,
ki a le dá wọn lare; nwọn o si gbọ́, nwọn
o si wipe, Õtọ ni.
10 Ẹnyin li ẹlẹri mi, ni Oluwa wi, ati
iranṣẹ mi ti mo ti yàn: ki ẹnyin ki o le
mọ̀ ki ẹ si gbà mi gbọ́ ki o si ye nyin pe,
Emi ni; a kò mọ̀ Ọlọrun kan ṣãju mi, bẹ̃ni
ọkan kì yio si hù lẹhin mi.
11 Emi, ani emi ni Oluwa; ati lẹhin
mi, kò si olugbala kan.
12 Emi ti sọ, mo ti gbalà, mo si ti fi hàn,
nigbati ko si ajeji ọlọrun kan lãrin nyin:
ẹnyin ni iṣe ẹlẹri mi, li Oluwa wi, pe, Emi
li Ọlọrun.
13 Lõtọ, ki ọjọ ki o to wà, Emi na ni,

Digitized by Google

ko si si ẹniti o le gbani kuro li ọwọ́ mi:
emi o ṣiṣe, tani o le yi i pada?
14 Bayi li Oluwa, olurapada nyin, Ẹni-
Mimọ Israeli wi; Nitori nyin ni mo se
ransẹ si Babiloni, ti mo si jù gbogbo wọn
bi isansa, ati awọn ara Kaldea sisalẹ, si
awọn ọkọ̀ igbe-ayọ̀ wọn.
15 Emi ni Oluwa, Ẹni-Mimọ́ nyin, ẹlẹda
Israeli Ọba nyin.
16 Bayi li Oluwa wi, ẹniti o la ọ̀na ninu
okun, ati ipa-ọ̀na ninu alagbara omi;
17 Ẹniti o mu kẹkẹ ati ẹṣin jade, ogun
ati agbara; nwọn o jumọ dubulẹ, nwọn kì
yio dide: nwọn run, a pa wọn bi owú
fitila.
18 Ẹ máṣe ranti nkan ti iṣaju mọ, ati
nkan ti atijọ, ẹ máṣe rò wọn.
19 Kiyesi i, emi o ṣe ohun titùn kan;
nisisiyi ni yio hù jade; ẹnyin ki yio mọ̀ ọ
bi? lõtọ, emi o là ọ̀na kan ninu aginju, ati
odò li aṣalẹ̀.
20 Awọn ẹran igbẹ yio yìn mi logo,
awọn dragoni ati awọn owiwi; nitori emi
o funni li omi li aginjù, ati odo ni aṣalẹ̀,
lati fi ohun mimu fun awọn enia mi,
ayanfẹ mi;
21 Awọn enia yi ni mo ti mọ fun ara
mi; nwọn o fi iyìn mi hàn.
22 Ṣugbọn iwọ kò ké pe mi, Jakobu;
ṣugbọn ārẹ̀ mu ọ nitori mi, iwọ Israeli.
23 Iwọ ko mu ọmọ-ẹran ẹbọ sisun rẹ
fun mi wá; bẽni iwọ ko fi ẹbọ rẹ bu ọlá
fun mi. Emi ko fi ọrẹ mu ọ sìn, emi ko si
fi turari da ọ li agara.
24 Iwọ ko fi owo rà kalamu olõrun didun
fun mi, bẽni iwọ ko fi ọra ẹbọ rẹ yó mi;
ṣugbọn iwọ fi ẹ̀ṣẹ rẹ mu mi ṣe lãla, iwọ si fi
aiṣedẽde rẹ da mi li agara.
25 Emi, ani emi li ẹniti o pa irekọja rẹ
rẹ́ nitori ti emi tikalami, emi ki yio si
ranti ẹ̀ṣẹ rẹ.
26 Rán mi leti: ki a jumọ sọ ọ; iwọ rò,
ki a le da ọ lare.
27 Baba rẹ iṣãju ti ṣẹ̀, awọn olukọni rẹ
ti yapa kuro lọdọ mi.
28 Nitorina mo ti sọ awọn olori ibi
mimọ́ na di aimọ́, mo si ti fi Jakobu fun
egún, ati Israeli fun ẹ̀gan.

## ORI 44.

ṢUGBỌN nisisiyi, gbọ́, iwọ Jakobu iranṣẹ
mi, ati Israeli ẹniti mo ti yàn:
2 Bayi ni Oluwa wi ẹniti o dá ọ, ti o mọ
ọ lati inu wá, ti yio si ràn ọ lọwọ; Má bẹ̀ru,
iwọ Jakobu, iranṣẹ mi; ati iwọ Jeṣuruni ti
mo ti yàn.
3 Nitori emi o dà omi lu ẹniti ongbẹ
ngbẹ, ati iṣàn-omi si ilẹ gbigbẹ: emi o dà
ẹmi mi si iru rẹ, ati ibukun mi si iru-ọmọ
rẹ.
4 Nwọn o si hù soke lãrin koriko, bi igi
willo leti ipadò.
5 Ọkan yio wipe, ti Oluwa li emi, omi-
ran yio si pe ara rẹ̀ nipa orukọ Jakobu;
omiran yio si fi ọwọ́ rẹ̀ kọ pe, on ni ti
Oluwa, yio si pe apele rẹ̀ nipa orukọ Israeli.
6 Bayi ni Oluwa wi, Ọba Israeli, ati
Olurapada rẹ, Oluwa awọn ọmọ-ogun;
Emi ni ẹni-ikini, ati ẹni-ikẹhin; ati lẹhin
mi *ko* si Ọlọrun kan.
7 Tani yio si pè bi emi, ti yio si sọ ọ, ti
yio si tò o lẹsẹ-ẹsẹ fun mi, lati igbati mo
ti yàn awọn enia igbani? ati nkan wọnni
ti mbọ̀, ti yio si ṣẹ, ki nwọn fi hàn fun wọn.
8 Ẹ má bẹ̀ru, ẹ má si foyà; emi ko ha
ti mu nyin gbọ́ lati igba na wá, nkò ha si
ti sọ ọ? ẹnyin na ni ẹlẹri mi. Ọlọrun kan
mbẹ lẹhin mi bi? kò si Apata kan, emi ko
mọ̀ ọkan.
9 Asan ni gbogbo awọn ti ngbẹ ere;
nkan iyebiye wọn ki yio si lerè; awọn
tikala wọn li ẹlẹri ara wọn: nwọn kò riran,
bẽni nwọn kò mọ̀; ki oju ba le tì wọn.
10 Tani yio gbẹ́ oriṣa, tabi ti yio dà ere
ti kò ni ère kan?
11 Kiyesi i, oju o tì gbogbo awọn ẹgbẹ́
rẹ̀; awọn oniṣọna, enia ni nwọn: jẹ ki
gbogbo wọn kò ara wọn jọ, ki nwọn dide
duro; nwọn o bẹ̀ru, oju o si jumọ tì wọn.
12 Alagbẹdẹ rọ ãke kan, o ṣiṣẹ ninu
ẹyín, o fi ọmọ-owú rọ ọ, o si fi agbara apá
rẹ̀ ṣe e: ebi npa a pẹlu, agbara rẹ̀ si tan;
ko mu omi, o si rẹ̀ ẹ.
13 Gbẹnàgbẹnà ta okùn rẹ̀, o si fi nkan
pupa sàmi rẹ̀, o fi ìfá fá a, o si fi kọmpassi
là a birikiti: o sì yá a li aworán ọkọnrin,
gẹgẹ bi ẹwà enia, ki o le ma gbe inu ile.
14 O bẹ́ igi kedari lu ilẹ fun ra rẹ̀, o si
mu igi kipressi ati oaku, o si mu u le fun
ra rẹ̀ ninu awọn igi igbó: o gbìn igi aṣi,
ojò si mu u dagba.
15 Nigbana ni yio jẹ ohun idana fun
enia: nitori yio mu ninu wọn, yio si fi yá
iná; lõtọ, o dá iná, o si din akara, lõtọ, o
ṣe ọlọrun fun ra rẹ̀, o si nsìn i; o gbẹ ẹ li
ere, o si nforibalẹ fun u.
16 Apakan ninu rẹ̀ li o fi dá iná, apakan
ninu rẹ̀ li o fi jẹ ẹran: o sun sisun, o si yo,
o yá iná pẹlu, o si wipe, Ahã, ara mi gbona,
mo ti ri iná.
17 Iyokù rẹ̀ li o si fi ṣe ọlọrun, ani ere
gbigbẹ́ rẹ̀, o foribalẹ fun u, o sìn i, o gba-

dura si i, o si wipe, Gbà mi ; nitori iwọ li
ọlọrun mi.
18 Nwọn kò mọ̀, oye ko si ye wọn:
nitori o dí wọn li oju, ki nwọn ki o má le
ri ; ati aiya won, ki oye ki o má le ye wọn.
19 Kò si ẹniti o rọ̀ li ọkàn rẹ̀, bẽni ko si
imọ̀ tabi oye lati wipe, Mo ti fi apakan rẹ̀
da iná ; mo si din akara pẹlu lori ẹyin iná
rẹ̀ : mo ti sun ẹran, mo si jẹ ẹ : emi o ha
fi iyokù rẹ̀ ṣe irira ? emi o ha foribalẹ fun
ìti igi ?
20 O fi ẽru bọ́ ara rẹ̀ : aiya ẹtàn ti dari
rẹ̀ si apakan, ti kò le gbà ọkàn rẹ̀ là, bẽni
kò le wipe, Eke ko ha wà li ọwọ́ ọtun mi ?
21 Ranti wọnyi, Jakobu ati Israeli;
nitori iwọ ni iranṣẹ mi: Emi ti mọ ọ;
iranṣẹ mi ni iwọ, Israeli; iwọ ki yio di
ẹni-igbagbe lọdọ mi.
22 Mo ti pa irekọja rẹ rẹ́, bi awọsanma
ṣiṣú dùdu, ati ẹ̀ṣẹ rẹ, bi kũku: yipada sọdọ
mi ; nitori mo ti rà ọ pada.
23 Kọrin, ẹnyin ọrun ; nitori Oluwa ti
ṣe e : kigbe, ẹnyin isalẹ aiye ; bú si orin,
ẹnyin oke-nla, igbó, ati gbogbo igi inu rẹ̀ ;
nitori Oluwa ti rà Jakobu pada, o si ṣe ara
rẹ̀ logo ni Israeli.
24 Bayi li Oluwa, Olurapada rẹ wi, ati
ẹniti o mọ ọ lati inu wá : emi li Oluwa ti o
ṣe ohun gbogbo ; ti o nikan nà awọn ọrun;
ti mo si tikara mi tẹ́ aiye.
25 Ẹniti o sọ àmi awọn eke di asan, ti o
si bà awọn alafọṣẹ li ori jẹ, ti o dá awọn
ọlọgbọn pada, ti o si sọ imọ̀ wọn di wère.
26 Ti o fi ìdi ọ̀rọ iranṣẹ rẹ̀ mulẹ, ti o si
mu ìmọ awọn ikọ̀ rẹ̀ ṣẹ ; ti o wi fun Jeru-
salemu pe, A o tẹ̀ ọ dó ; ati fun gbogbo ilu
Juda pe, A o kọ́ nyin, emi o si gbe gbogbo
ahoro rẹ̀ dide :
27 Ti o wi fun ibú pe, Gbẹ, emi o si mu
gbogbo odò rẹ gbẹ.
28 Ti o wi niti Kirusi pe, Oluṣọ-agutan
mi ni, yio si mu gbogbo ifẹ mi ṣẹ : ti o wi
niti Jerusalemu pe, A o kọ́ ọ: ati niti
tempili pe, A o fi ipilẹ rẹ sọlẹ.

## ORI 45.

BAYI ni Oluwa wi fun ẹni-ororo rẹ̀, fun
Kirusi, ẹniti mo di ọwọ́ ọtún rẹ̀ mu,
lati ṣẹ́gun awọn orilẹ-ède niwaju rẹ̀ ; emi o
si tú amure ẹgbẹ awọn ọba, lati ṣi ilẹkùn
mejeji niwaju rẹ̀, a ki yio si tì àṣẹ na ;
2 Emi o lọ siwaju rẹ, emi o si sọ ibi
wiwọ́ wọnni di titọ́ : emi o fọ ilẹkùn idẹ
wọnni tũtũ, emi o si ke ọjá-irin si meji.
3 Emi o si fi iṣura okùnkun fun ọ, ati
ọrọ̀ ti a pamọ nibi ikọkọ, ki iwọ le mọ̀ pe,
emi Oluwa, ti o pè ọ li orukọ rẹ, li Ọlọrun
Israeli.
4 Nitori Jakobu iranṣẹ mi, ati Israeli
ayanfẹ mi, emi ti pè ọ li orukọ rẹ : mo ti
fi apele kan fun ọ, bi iwọ ko tilẹ ti mọ̀ mi.
5 Emi li Oluwa, ko si ẹlomiran, kò si
Ọlọrun kan lẹhin mi : mo dì ọ li àmure, bi
iwọ kò tilẹ̀ ti mọ̀ mi.
6 Ki nwọn le mọ̀ lati ila-õrun, ati lati
iwọ-õrun wá pe, ko si ẹnikan lẹhin mi ;
Emi ni Oluwa, ko si ẹlomiran.
7 Mo dá imọlẹ, mo si dá okunkun : mo
ṣe alafia, mo si dá ibi : Emi Oluwa li o ṣe
gbogbo wọnyi.
8 Kán silẹ, ẹnyin ọrun, lati oke wá, ki
ẹ si jẹ ki ofurufu rọ̀ ododo silẹ ; jẹ ki ilẹ ki
o là, ki o si mu igbala jade ; si jẹ ki ododo
ki o hù soke pẹlu rẹ ; Emi Oluwa li o dá a.
9 Egbe ni fun ẹniti o mbá Ẹlẹda rẹ̀ jà,
apãdi ninu awọn apãdi ilẹ ! Amọ̀ yio ha wi
fun ẹniti o mọ ọ pe, Kini iwọ nṣe ; tabi iṣẹ
rẹ pe, On kò li ọwọ́ ?
10 Egbe ni fun ẹniti o wi fun baba rẹ̀
pe, Kini iwọ bi ? tabi fun obirin nì pe,
Kini iwọ bi ?
11 Bayi li Oluwa wi, Ẹni-Mimọ Israeli,
ati Ẹlẹda rẹ̀, Bere nkan ti mbọ̀ lọwọ mi,
niti awọn ọmọ mi ọkọnrin, ati niti iṣẹ ọwọ
mi, ẹ paṣẹ fun mi.
12 Mo ti dá aiye, mo si ti da enia sori
rẹ̀ ; Emi, ani ọwọ́ mi, li o ti nà awọn ọrun,
gbogbo awọn ogun wọn ni mo si ti paṣẹ fun.
13 Mo ti gbe e dide ninu ododo, emi o si
mu gbogbo ọ̀na rẹ̀ tọ́ ; on o kọ́ ilu mi, yio
si dá awọn ondè mi silẹ : ki iṣe fun iye owo
tabi ère, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
14 Bayi li Oluwa wi, pe, Ere iṣẹ Egipti,
ati ọjà Etiopia ati ti awọn ara Sabea, awọn
enia ti o ṣigbọnlẹ yio kọja wá sọdọ rẹ,
nwọn o si jẹ tirẹ: nwọn o tẹle ọ ; ninu
ẹwọ̀n ni nwọn o kọja wá, nwọn o foribalẹ
fun ọ, nwọn o si bẹ̀ ọ, wipe, Nitotọ Ọlọrun
wà ninu rẹ ; kò si si ẹlomiran, kò si Ọlọrun
miran.
15 Lõtọ iwọ li Ọlọrun ti o fi ara rẹ pamọ,
Ọlọrun Israeli, Olugbala.
16 Oju yio tì wọn, gbogbo wọn o si
dãmu pọ̀ ; gbogbo awọn ti nṣe ere yio si
jumọ lọ si idãmu.
17 Ṣugbọn a o fi igbala ainipẹkun gba
Israeli là ninu Oluwa : oju ki yio tì nyin,
bẽni ẹ ki yio dãmu aiye ainipẹkun.
18 Nitori bayi li Oluwa wi, ẹniti o dá
awọn ọrun ; Ọlọrun tikararẹ̀ ti o mọ aiye,
ti o si ṣe e ; o ti fi idi rẹ̀ mulẹ, kò da a

Digitized by Google

lasan, o mọ ọ ki a le gbe inu rẹ̀: Emi ni
Oluwa; ko si ẹlomiran.
19 Emi kò sọrọ ni ikọkọ ni ibi okùnkun
aiye: Emi kò wi fun iru-ọmọ Jakobu pe,
Ẹ wá mi lasan: emi Oluwa li o nsọ ododo,
mo fi nkan wọnni ti o tọ́ hàn.
20 Ko ara nyin jọ ki ẹ si wá; ẹ jọ
sunmọ tosi, ẹnyin ti o salà ninu awọn
orilẹ-ède; awọn ti o gbé igi ere gbigbẹ́ wọn
kò ni ìmọ, nwọn si gbadura si ọlọrun ti ko
le gba ni.
21 Ẹ sọ ọ, ki ẹ si mu wá, lõtọ, ki nwọn
ki o jọ gbimọ̀ pọ̀: tali ọ mu ni gbọ́ eyi lati
igbãni wa? tali o ti sọ ọ lati igba na wá?
emi Oluwa kọ? ko si Ọlọrun miran pẹlu
mi; Ọlọrun ododo ati Olugbala; ko si
ẹlomiran lẹhin mi.
22 Kọju si mi, ki a si gba nyin là, gbo-
gbo opin aiye: nitori emi li Ọlọrun, ko si
ẹlomiran.
23 Mo ti fi ara mi bura, ọ̀rọ na ti ti ẹnu
mi ododo jade, ki yio si pada, pe, Gbogbo
ẽkún yio kunlẹ fun mi, gbogbọ ahọn yio
bura.
24 Lõtọ, a o wipe, ninu Oluwa li emi ni
ododo ati agbara: sọdọ rẹ̀ ni gbogbo enia
yio wá; oju o si tì gbogbo awọn ti o binu
si i.
25 Ninu Oluwa li a o dá gbogbo iru-ọmọ
Israeli lare, nwọn o si ṣogo.

## ORI 46.

BELI tẹriba, Nebo bẹrẹ̀, oriṣa wọn wà
lẹhin awọn ẹranko, ati lẹhin ohunọ-
sìn; a di ẹrù wiwo rù nyin; ẹrù fun awọn
ẹranko ti ãrẹ̀ mu.
2 Nwọn bẹ̀rẹ, nwọn jumọ tẹriba; nwọn
kò le gbà ẹrù na silẹ, ṣugbọn awọn tikala
wọn lọ si igbèkun.
3 Gbọ́ ti emi, iwọ ile Jakobu, ati gbogbo
iyoku ile Israeli, ti mo ti gbe lati inu wá,
ti mo ti rù lati inu iyá wá.
4 Ani titi de ogbó Emi na ni; ani titi
de ewú li emi o rù nyin; emi ti ṣe e, emi o
si gbe, nitõtọ emi o rù, emi o si gbàla.
5 Tani ẹnyin o fi mi we, ti yio si ba mi
dọgba, ti ẹ o si fi mi jọ, ki awa le jẹ ọ̀gba?
6 Nwọn da wura lati inu apò wá, nwọn
si fi iwọ̀n wọ̀n fadaka, nwọn bẹ̀ alagbẹdẹ
wura, o fi si ṣe oriṣa: nwọn tẹriba, nwọn
si nsìn.
7 Nwọn gbe e le ejika, nwọn rù u, nwọn
si fi i sipò rẹ̀; o si duro: ki yio kuro ni ipò
rẹ̀: nitõtọ, ẹnikan yio kọ si i, ṣugbọn ki
yio dahùn: bẹ̃ni ki yio gbà a kuro ninu
wahala rẹ̀.
8 Ẹ ranti eyi, ẹ si fi ara nyin hàn bi
ọkọnrin: ẹ gbà a si ọkàn, ẹnyin alarekọja.
9 Ẹ ranti nkan iṣaju atijọ; nitori emi li
Ọlọrun, ko si si ẹlomiran, emi li Ọlọrun,
ko si si ẹniti o dabi emi.
10 Ẹniti nsọ opin lati ipilẹṣẹ wá, ati
nkan ti kò ti iṣe lati igbãni wá, wipe, Imọ
mi yio duro, emi o si ṣe gbogbo ifẹ mi.
11 Ẹniti npe idì lati ilà-õrun wá: ọkọn-
rin na ti o mu ìmọ mi ṣẹ lati ilẹ jijìn wá:
lõtọ, emi ti sọ ọ, emi o si mu u ṣẹ; emi ti
pinnu rẹ̀, emi o si ṣe e pẹlu.
12 Gbọ́ ti emi, ẹnyin alagidi ọkàn, ti o
jinà si ododo:
13 Emi mu ododo mi sunmọ tosí; ki
yio si jina réré, igbala mi ki yio si duro pẹ́:
emi o si fi igbala si Sioni fun Israeli ogo mi.

## ORI 47.

SỌKALẸ, si joko ninu ekuru, iwọ wundia
ọmọbirin Babiloni, joko ni ilẹ: itẹ́ kò
si, iwọ ọmọbirin ara Kaldea: nitori a kì o
pè ọ ni ẹlẹ́gẹ on aláfẹ mọ.
2 Gbe ọlọ, si lọ̀ iyẹfun, ṣi iboju rẹ,
ká aṣọ ẹsẹ, ká aṣọ itan, là odo wọnni
kọja.
3 A o ṣi ihoho rẹ, a o si ri itiju rẹ pẹlu;
emi o gbẹsan, enia kì yio sí lati da mi
ro.
4 Olurapada wa, Oluwa awọn ọmọ-ogun
li orukọ rẹ̀, Ẹni-Mimọ Israeli.
5 Joko, dakẹ jẹ, lọ sinu okùnkun, iwọ
ọmọbirin ara Kaldea, nitori a ki yio pe ọ
ni Iyálode awọn ijọba mọ.
6 Emi ti binu si enia mi, emi ti sọ ilẹ
ini mi di aimọ́, mo si ti fi wọn le ọ lọwọ:
iwọ kò kãnu wọn, iwọ fi ajàga wuwo le
awọn alagbara lori.
7 Iwọ si wipe, Emi o ma jẹ Iyalode titi
lai: bẹ̃ni iwọ kò fi nkan wọnyi si aiya rẹ,
bẹ̃ni iwọ kò ranti igbẹhin rẹ.
8 Nitorina gbọ́ ẹyi, iwọ alafẹ́, ti o joko
li ainani, ti o wi li ọkàn rẹ pe, Emi ni, kò
si si ẹlomiran lẹhin mi: emi ki yio joko bi
opo, bẹ̃ni emi ki yio mọ̀ òfo ọmọ.
9 Ṣugbọn nkan meji wọnyi ni yio deba
ọ li ojiji, li ọjọ kan, òfo ọmọ ati opo: nwọn
o ba ọ perepere, nitori ọpọlọpọ iṣe ajẹ́ rẹ,
ati nitori ọpọlọpọ iṣe afọṣẹ rẹ.
10 Nitori ti iwọ ti gbẹkẹle ìwa buburu
rẹ: iwọ ti wipe, Kò si ẹnikan ti o ri mi.
Ọgbọ́n rẹ ati ìmọ rẹ, o ti mu ọ ṣinà; iwọ
si ti wi li ọkàn rẹ pe, Emi ni, ko si ẹlọ-
miran lẹhin mi.
11 Nitorina ni ibi yio ṣe ba ọ; iwọ ki
yio mọ̀ ibẹrẹ rẹ̀: ibi yio si ṣubu lù ọ; ti

Digitized by Google

iwọ kì yio le mu kuro : idahoro yio deba ọ
lojiji, iwọ kì yio si mọ̀.
12 Duro nisisiyi, ti iwọ ti iṣẹ afọṣẹ rẹ,
ati ọpọlọpọ iṣe ajẹ́ rẹ, eyi ti o ti fi nṣe iṣẹ
iṣe lati igba ewe rẹ wá ; bi o ba ṣepe o lè jẹ
erè fun ọ, bi o ba ṣe pe iwọ lè bori.
13 Arẹ̀ mu ọ nipa ọpọlọpọ ìgbimọ rẹ.
Jẹ ki awọn awoye-ọrun, awọn awoye-irawọ,
awọn afi-oṣupasọ-asọtẹlẹ, dide duro nisisiyi,
ki nwọn si gbà ọ lọwọ nkan wọnyi ti yio
ba ọ.
14 Kiye si i, nwọn o dabi akekù koriko :
iná yio jo wọn : nwọn ki yio gba ara wọn
lọwọ agbara ọwọ́ iná ; ẹyin iná kan ki yio
si lati yá, tabi iná lati joko niwaju rẹ.
15 Bayi ni awọn ti iwọ ti ba ṣiṣẹ yio jẹ
fun ọ, awọn oniṣowo rẹ, lati ewe rẹ wá ;
nwọn o kiri lọ, olukuluku si ẹkùn rẹ̀ ; ko
si ẹnikan ti yio gbà ọ.

## ORI 48.

GBỌ́ eyi, ẹnyin ile Jakobu, ti a nfi orukọ
Israeli pè, ti o si ti inu omi Juda
wọnni jade wá, ti o nfi orukọ Oluwa bura,
ti o si ndarukọ Ọlọrun Iṣraeli, ṣugbọn ki
iṣe li otitọ, tabi li ododo.
2 Nitori nwọn npè ara wọn ni ti ilu
mimọ́ nì, nwọn si gbé ara wọn le Ọlọrun
Israeli : Oluwa awọn ọmọ-ogun li orukọ
rẹ̀.
3 Emi ti sọ nkan ti iṣãju wọnni lati ipi-
lẹṣẹ ; nwọn si ti jade lati ẹnu mi lọ, emi
si fi wọn hàn ; emi ṣe wọn lojijì, nwọn si
ti ṣẹ.
4 Nitori emi mọ̀ pe olori-lile ni iwọ, ọrùn
rẹ jẹ iṣan irin, iwaju rẹ si jẹ idẹ.
5 Li atetekọṣe ni mo tilẹ ti sọ fun ọ ; ki
o to de ni emi ti fi ihàn ọ : ki iwọ má
ba wipe, Oriṣa mi li o ṣe wọn, ati ere mi
gbigbẹ́, ati ere mi didà li o ti pa wọn li
aṣẹ.
6 Iwọ ti gbọ́, wò gbogbo eyi ; ẹnyin kì
yio ha sọ ọ ? Emi ti fi ohun titun hàn ọ
lati igba yi lọ, ani nkan ti o lumọ́, iwọ kò
si mọ̀ wọn.
7 Nisisiyi li a dá wọn, ki isi ṣe li ate-
tekọṣe ; ani ṣaju ọjọ na ti iwọ kò gbọ́
wọn ; ki iwọ má ba wipe, Kiyesi i, emi
mọ̀ wọn.
8 Lõtọ, iwọ kò gbọ́ ; lõtọ, iwọ kò mọ̀ ;
lõtọ lati igba na eti rẹ kò ṣi : nitori ti
emi mọ̀ pe, iwọ o hùwa arekerekè, gidigidi
li a si pè ọ li olurekọja lati inu wá.
9 Nitori orukọ mi emi o mu ibinu mi
pẹ, ati nitori iyìn mi, emi o fàsẹhin nitori
rẹ, ki emi má ba ké ọ kuro.
10 Wò o, emi ti dà ọ, ṣugbọn ki iṣe
bi fadaka ; emi ti yàn ọ ninu iná ileru
wahala.
11 Nitori emi tikalami, ani nitori ti emi
tikala mi, li emi o ṣe e, nitori a o ha ṣe bà
orukọ mi jẹ ? emi kì yio si fi ogo mi fun
ẹlomiran.
12 Gbọ́ ti emi, iwọ Jakobu, ati Israeli,
ẹni-ipè mi ; Emi na ni ; emi li ẹni-ikini,
ati ẹni-ikẹhin.
13 Ọwọ́ mi pẹlu li o si ti fi ipilẹ aiye
sọlẹ, atẹlẹwọ ọtun mi li o si na awọn
ọrun : nigbati mo pè wọn, nwọn jumọ dide
duro.
14 Gbogbo nyin, ẹ pejọ, ẹ si gbọ́ ; tani
ninu wọn ti o ti sọ nkan wọnyi ? Oluwa ti
fẹ́ ẹ : yio si ṣe ifẹ rẹ̀ ni Babiloni, apá rẹ̀ yio
si wà lara awọn ara Kaldea.
15 Emi, ani emi ti sọ ọ ; lõtọ emi ti pè
e : emi ti mu u wá, on o si mu ọ̀na rẹ̀ ṣe
dẽde.
16 Ẹ sunmọ ọdọ mi, ẹ gbọ́ eyi ; lati ipi-
lẹ̀ṣẹ emi kò sọ̀rọ ni ikọ̀kọ ; lati igbati o ti
wà, nibẹ ni mo wà ; ati nisisiyi Oluwa
Jehofa, on Ẹmi rẹ̀, li o ti rán mi.
17 Bayi li Oluwa wi, Olurapada rẹ, Ẹni-
Mimọ Israeli : Emi li Oluwa Ọlọrun rẹ, ti
o kọ́ ọ fun èrè, ẹniti o tọ́ ọ li ọ̀na ti iwọ iba
ma lọ.
18 Ibaṣepe iwọ fi eti si ofin mi ! nigbana
ni alafia rẹ iba dabi odo, ati ododo rẹ bi
ìgbi-omi okun.
19 Iru-ọmọ rẹ pẹlu iba dabi iyanrìn, ati
ọmọ-bibi inu rẹ bi tãra rẹ̀ ; a ki ba ti ke
orukọ rẹ̀ kuro, bẹ̃ni a kì ba pa a run kuro
niwaju mi.
20 Ẹ jade kuro ni Babiloni, ẹ sá kuro
lọdọ awọn ara Kaldea, ẹ fi ohùn orin sọ ọ,
wi eyi, sọ ọ jade titi de opin aiye ; ẹ wipe,
Oluwa ti rà Jakobu iranṣẹ rẹ̀ pada.
21 Ongbẹ kò si gbẹ́ wọn, nigbati o mu
wọn là aginjù wọnni ja ; o mu omi ṣàn
jade lati inu apata fun wọn, o sán apáta
pẹlu, omi si tú jade.
22 Alafia kò si fun awọn enia buburu, li
Oluwa wi.

## ORI 49.

EGBỌ ti emi, ẹnyin erekùṣu ; ki ẹ si fi
etí silẹ, ẹnyin enia lati ọ̀na jijìn wá ;
Oluwa ti pè mi lati inu wá ; lati inu iya
mi li o ti dá orukọ mi.
2 O si ti ṣe ẹnu mi bi idà mimú ; ninu
ojiji ọwọ́ rẹ̀ li o ti pa mi mọ, o si sọ mi
di ọfà didán ; ninu apó rẹ̀ li o ti pa mi
mọ́ ;

Digitized by Google

3 O si wi fun mi pe, Iwọ ni iranṣẹ mi,
Israeli, ninu ẹniti a o yìn mi logo.
4 Nigbana ni mo wi pe, Emi ti ṣiṣẹ́ lasan,
emi ti lò agbara mi lofo, ati lasan: nitõtọ
idajọ mi mbẹ lọdọ Oluwa, ati iṣẹ mi lọdọ
Ọlọrun mi.
5 Ati nisisiyi, li Oluwa wi, ẹni ti o mọ
mi lati inu wá lati ṣe iranṣẹ rẹ̀, lati mu
Jakobu pada wá sọdọ rẹ̀, lati ṣà Israeli jọ,
ki emi le ni ogo loju Oluwa, Ọlọrun mi yio
si jẹ́ agbara mi.
6 O si wipe, O ṣe ohun kekere ki iwọ
ṣe iranṣẹ mi, lati gbe awọn ẹyà Jakobu
dide, ati lati mu awọn ipamọ Israeli pada:
emi o si fi ọ ṣe imọlẹ awọn Keferi, ki iwọ
ki o le ṣe igbala mi titi de opin aiye.
7 Bayi ni Oluwa, Olurapada Israeli, ati
Ẹni-Mimọ rẹ wi, fun ẹniti enia ngàn, fun
ẹniti orilẹ-ède korira, fun iranṣẹ awọn
olori, pe, Awọn ọba yio ri, nwọn o si dide,
awọn ọmọ-alade pẹlu yio wolẹ sìn, nitori
Oluwa ti iṣe olõtọ, Ẹni-Mimọ Israeli, on li
o yàn ọ.
8 Bayi ni Oluwa wi, Li akoko itẹwọgba
emi ti gbọ́ tirẹ, ati li ọjọ igbala, mo si ti
ràn ọ lọwọ: emi o si pa ọ mọ, emi o si
fi ọ ṣe majẹmu awọn enia, lati fi idi aiye
mulẹ, lati mu ni jogun ahoro ilẹ nini
wọnni.
9 Ki iwọ ki o le wi fun awọn igbekùn
pe, Ẹ jade lọ; fun awọn ti o wà ni okùn-
kun pe, Ẹ fi ara nyin hàn. Nwọn o jẹ̀ li
ọ̀na wonni, pápa ijẹ wọn o si wà ni gbogbo
ibi giga.
10 Ebi kì yio pa wọn, bẹ̃ni ongbẹ kì yio
si gbẹ wọn; oru kì yio mu wọn, bẹ̃ni õrùn
kì yio si pa wọn: nitori ẹniti o ti ṣãnu fun
wọn yio tọ́ wọn, ani nihà isun omi ni yio
dà wọn.
11 Emi o si sọ gbogbo awọn okenla mi
wọnni di ọ̀na, a o si gbe ọ̀na opopo mi
wọnni ga.
12 Kiye si i, awọn wọnyi yio wá lati ọ̀na
jijìn: si wò o, awọn wọnyi lati ariwa wá;
ati lati yama wá, ati awọn wọnyi lati ilẹ
Sinimu wá.
13 Kọrin, ẹnyin ọrun; ki o si yọ̀, iwọ
aiye; bú jade ninu orin, ẹnyin oke-nla:
nitori Oluwa ti tù awọn enia rẹ̀ ninu, yio
si ṣãnu fun awọn olupọnju rẹ̀.
14 Ṣugbọn Sioni wipe, Oluwa ti kọ̀ mi
silẹ; Oluwa mi si ti gbagbe mi.
15 Obirin ha lè gbagbe ọmọ ọmú rẹ̀ bi,
ti kì yio fi ṣe iyọ́nu si ọmọ inu rẹ̀? lõtọ,
nwọn le gbagbe, ṣugbọn emi kì yio gbagbe
rẹ.
16 Kiye si i, emi ti kọ ọ si atẹlẹwọ mi:
awọn odi rẹ mbẹ niwaju mi nigbagbogbo.
17 Awọn ọmọ rẹ yára; awọn oluparun
rẹ ati awọn ti o fi ọ ṣòfò yio ti ọdọ rẹ jade.
18 Gbe oju rẹ soke yika kiri, si kiyesi i:
gbogbo awon wọnyi ṣà ara wọn jọ, nwọn si
wá sọdọ rẹ. Oluwa wipe, Bi mo ti wà,
iwọ o fi gbogbo wọn bò ara rẹ, bi ohun ọṣọ́,
nitõtọ, iwọ o si há wọn mọ ara, bi iyawo.
19 Nitori ibi ofò rẹ, ati ibi ahoro rẹ
wọnni, ati ilẹ iparun rẹ, yio tilẹ há jù nisi-
siyi, nitori awọn ti ngbe inu wọn, awọn
ti o gbe ọ mì yio si jinà réré.
20 Awọn ọmọ-ọmọ rẹ ti o ti nù yio tun
wi li eti rẹ pe, Ayè kò gbà mi, fi ayè fun
mi lati ma gbé.
21 Nigbana ni iwọ o wi li ọkàn rẹ pe,
Tali o bi awọn wọnyi fun mi, mo sa ti wà
li ailọmọ ati li àgan, igbèkun ati ẹni-iṣiki-
ri? tani o si ti tọ́ awọn wọnyi dagba? Ki-
yesi i, a fi emi nikan silẹ, awọn wọnyi,
nibo ni nwọn gbe ti wà.
22 Bayi ni Oluwa Jehofa wi, Kiyesi i,
emi o gbe ọwọ́ mi soke si awọn Keferi, emi
o si gbe ọpágun mi soke si awọn enia, nwọn
o si gbe awọn ọmọkọnrin rẹ wá li apa wọn,
a o si gbe awọn ọmọbirin rẹ li ejìka wọn.
23 Awọn ọba yio jẹ baba olutọju rẹ,
awọn ayaba wọn yio si jẹ iya olutọju rẹ;
ni idojubolẹ ni nwọn o ma tẹriba fun ọ,
nwọn o si lá ekuru ẹsẹ rẹ; iwọ o si mọ̀ pe
emi li Oluwa; nitori oju kì yio tì awọn ti
o ba duro dè mi.
24 A ha le gba ikogun lọwọ alagbara
bi? tabi a le gbà awọn ondè lọwọ awọn
ẹniti nwọn tọ́ fun?
25 Ṣugbọn bayi ni Oluwa wi, a o tilẹ
gbà awọn ondè kuro lọwọ awọn alagbara, a
o si gbà ikogun lọwọ awọn ẹni-ẹ̀ru; nitori
ẹniti o mba ọ jà li emi o ba jà, emi o si gbà
awọn ọmọ rẹ là.
26 Awọn ti o ni ọ lara li emi o fi ẹran
ara wọn bọ́, nwọn o mu ẹjẹ ara wọn li
amuyo bi ọti-waini didùn: gbogbo ẹran-ara
yio si mọ̀ pe, Emi Oluwa ni Olugbala ati
Olurapada rẹ, Ẹni-alagbara ti Jakobu.

## ORI 50.

BAYI ni Oluwa wi, Nibo ni iwe ikọsilẹ
iyá nyin gbe wà, ẹniti mo ti kọ̀ silẹ?
tabi tani ninu awọn onigbese mi ti mo ti tà
nyin fun? Kiyesi i, nitori aiṣedẽde nyin li
ẹnyin ti tà ara nyin, ati nitori irekọja nyin
li a ṣe kọ̀ iyá nyin silẹ.
2 Nitori kini mo de, kò si ẹnikan? ni-
gbati mo pè, kò si ẹnikan lati dahùn?

Digitized by Google

Ọwọ́ mi ha kuru tobẽ ti kò fi le rapada?
tabi emi kò ha li agbara lati gbani? kiyesi
i, ni ibawi mi mo gbẹ okun, mo sọ odò nla
di aginjù, ẹja wọn nrùn nitori ti omi kò si,
nwọn si kú fun ongbẹ.
3 Mo fi ohun dúdu wọ̀ awọn ọrun, mo si
fi aṣọ ọfọ̀ ṣe ibora wọn.
4 Oluwa Jehofa ti fi ahọn akẹ́kọ fun mi,
ki emi ki o le mọ̀ bi a iti sọ̀rọ li akokò fun
alãrẹ, o nji li oròwurọ̀, o ṣi mi li eti lati
gbọ́ bi akẹkọ.
5 Oluwa Jehofa ti ṣí mi li eti, emi kò si
ṣe aigbọràn, bẽni emi kò yipada.
6 Mo fi ẹ̀hìn mi fun awọn aluni, ati ẹ̀rẹ-
kẹ mi fun awọn ti ntú irun: emi kò pa
oju mi mọ́ kuro ninu itìju ati itutọ́ si.
7 Nitori Oluwa Jehofa yio ràn mi lọwọ:
nitorina emi kì yio dãmu; nitorina ni mo
ṣe gbe oju mi ró bi okuta lile, emi si mọ̀ pe
oju kì yio tì mi.
8 Ẹniti o dá mi lare wà ni tosí, tani o
ba mi jà? jẹ ki a duro pọ̀: tani iṣe ẹlẹ́jọ
mi? jẹ ki o sunmọ mi.
9 Kiye si i, Oluwa Jehofa yio ràn mi
lọwọ, tani o dá mi li ẹbi? wò o, gbogbo
wọn o di ogbó bi ẹwù; kokòro yio jẹ wọn
run.
10 Tani ninu nyin ti o bẹ̀ru Oluwa, ti o
gba ohùn iranṣẹ rẹ̀ gbọ́, ti nrìn ninu okùn-
kun, ti kò si ni imọlẹ? jẹ ki on gbẹkẹ̀le
orukọ Oluwa, ki o si fi ẹ̀hìn tì Ọlọrun rẹ̀.
11 Kiye si i, gbogbo ẹnyin ti o dá iná,
ti ẹ fi ẹta iná yi ara nyin ká: ẹ mã rìn
ninu imọlẹ ina nyin, ati ninu ẹta iná ti ẹ
ti dá. Eyi ni yio jẹ ti nyin lati ọwọ́ mi wá;
ẹnyin o dubulẹ ninu irora.

## ORI 51.

GBỌ́ ti emi, ẹnyin ti ntẹle ododo, ẹnyin
ti nwá Oluwa; wò apáta nì ninu eyiti
a ti gbẹ́ nyin, ati ihò kòto nì nibiti a gbe
ti wà nyin.
2 Ẹ wò Abrahamu baba nyin, ati Sara
ti o bi nyin; nitori on nikan ni mo pè, mo
si sure fun u, mo si mu u pọ̀ si i.
3 Nitori Oluwa yio tù Sioni ninu; yio
tù gbogbo ibi ofo rẹ̀ ninu; yio si ṣe aginju
rẹ̀ bi Edeni, ati aṣálẹ rẹ̀ bi ọgbà Oluwa,
ayọ̀ ati inudidùn li a o ri ninu rẹ̀, idupẹ,
ati ohùn orin.
4 Tẹtilelẹ si mi, ẹnyin enia mi; si fi eti
si mi, iwọ orilẹ-ède mi: nitori ofin kan yio
ti ọdọ mi jade lọ, emi o si gbe idajọ mi
kalẹ fun imọlẹ awọn enia.
5 Ododo mi wà nitosí; igbala mi ti jade
lọ, apá mi yio si ṣe idajọ awọn enia; awọn
erekùṣu yio duro dè mi, apá mi ni nwọn o
si gbẹkẹle.
6 Ẹ gbé ojú nyin soke si awọn ọrun, ki
ẹ si wò aiye nisalẹ: nitori awọn ọrun yio
fẹ́ lọ bi ẽfin, aiye o si di ogbó bi ẹwù, awọn
ti ngbe inu rẹ̀ yio si kú bakanna: ṣugbọn
igbala mi o wà titi lai, ododo mi kì yio si
parẹ́.
7 Gbọ́ ti emi, ẹnyin ti o mọ̀ ododo, enia
ninu aiya ẹniti ofin mi mbẹ; ẹ máṣe bẹ̀ru
ẹgàn awọn enia, ẹ má si ṣe foyà ẹsín wọn.
8 Nitori kòkoro yio jẹ wọn bi ẹ̀wu, idin
yio si jẹ wọn bi irun agutan: ṣugbọn odo-
do mi yio wà titi lai, ati igbala mi lati iran
de iran.
9 Ji, ji, gbe agbara wọ̀, Iwọ apa Oluwa;
ji, bi li ọjọ igbãni, ni iran atijọ. Iwọ kọ́
ha ke Rahabu, ti o si ṣá Dragoni li ọgbẹ́?
10 Iwọ kọ́ ha gbẹ okun, omi ibu nla
wọnni? ti o ti sọ ibú okun di ọ̀na fun awọn
ìrapada lati gbà kọja?
11 Nitorina awọn ẹni-ìrapada Oluwa yio
pada, nwọn o si wá si Sioni ti awọn ti
orin; ayọ̀ ainipẹkun yio si wà li ori wọn:
nwọn o ri inudidùn ati ayọ̀ gbà; ikãnu ati
ọ̀fọ yio fò lọ.
12 Emi, ani emi ni ẹniti ntù nyin ninu:
tani iwọ, ti iwọ o fi bẹ̀ru enia ti yio kú,
ati ọmọ enia ti a ṣe bi koriko.
13 Ti iwọ si gbagbe Oluwa Ẹlẹda rẹ ti o
ti nà awọn ọrun, ti o si ti fi ipilẹ aiye sọlẹ;
ti iwọ si ti mbẹ̀ru nigbagbogbo lojojumọ
nitori irúnu aninilara nì, bi ẹnipe o ti mura
lati panirun? nibo ni irúnu aninilara na
ha gbe wà?
14 Ondè ti a ti ṣí nipo yara ki a ba le tú
u silẹ, ati ki o má ba kú sinu ihò, tabi ki
onjẹ rẹ̀ má ba tán.
15 Ṣugbọn emi Oluwa Ọlọrun rẹ ti o pin
okun ni iyà, eyi ti ìgbi rẹ̀ nhó; Oluwa
awọn ọmọ-ogun ni orukọ rẹ̀.
16 Emi si ti fi ọ̀rọ mi si ẹnu rẹ, mo si ti
bò ọ mọlẹ ni ojiji ọwọ́ mi, ki emi ki o le
gbìn awọn ọrun, ki emi si le fi ipilẹ aiye
sọlẹ, ati ki emi le wi fun Sioni pe, Iwọ ni
enia mi.
17 Ji, ji, dide duro, iwọ Jerusalemu, ti
o ti mu li ọwọ́ Oluwa ago irúnu rẹ̀; iwọ ti
mu gẹ̀dẹgẹ́dẹ̀ ago ìwarìri, iwọ si fón wọn
jade.
18 Kò si ẹnikan ninu gbogbo awọn ọmọ
ọkọnrin ti o bí lati tọ́ ọ; bẽni kò si ẹniti o
fà a lọwọ, ninu gbogbo awọn ọmọ ọkọnrin
ti on tọ́ dàgba.
19 Ohun meji wọnyi li o débá ọ: tani o

Digitized by Google

kãnu fun ọ? idahoro, on iparun, ati ìyan,
on idà: nipa tani emi o tù ọ ninu?
20 Awọn ọmọ rẹ ọkọnrin ti dáku, nwọn
dubulẹ ni gbogbo ikorita, bi ẹfọ̀n ninu
àwọn: nwọn kún fun ìrúnu Oluwa, ibawi
Ọlọrun rẹ.
21 Nitorina gbọ́ eyi na, iwọ ẹniti a pọ́n
loju, ti o si mu amuyo, ṣugbọn kì iṣe nipa
ọti-waini:
22 Bayi ni Oluwa rẹ Jehofa wi, ati
Ọlọrun rẹ ti ngbèja enia rẹ̀, Kiyesi i, emi ti
gbà ago ìwárìri kuro lọwọ rẹ, gẹ̀dẹgẹ́dẹ̀ ago
irúnu mi; iwọ kì yio si mu u mọ.
23 Ṣugbọn emi o fi i si ọwọ́ awọn ti o
pọ́n ọ loju: ti nwọn ti wi fun ọkàn rẹ pe,
Wólẹ, ki a ba le rekọja: iwọ si ti tẹ́ ara rẹ
silẹ bi ilẹ, ati bi ita, fun awọn ti o rekọja.

ORI 52.

JI! ji! gbe agbara rẹ wọ̀, iwọ Sioni; gbe
aṣọ ogo rẹ wọ̀, iwọ Jerusalemu, ilu mi-
mọ́: nitori lati igbayi lọ, alaikọla on alai-
mọ́ kì yio wọ̀ inu rẹ mọ.
2 Gbọ̀n ekuru kuro li ara rẹ, dide, joko,
iwọ Jerusalemu: tú ọjá kuro li ọrùn rẹ,
iwọ ondè ọmọbirin Sioni.
3 Nitori bayi li Oluwa wi, a ti tà nyin
lọfẹ, a o si rà nyin pada laisanwo.
4 Nitori bayi li Oluwa Jehofa wi, Awọn
enia mi sọkalẹ lọ si Egipti li atijọ lati ṣe
atipo nibẹ; ara Assiria si ni wọn lara
lainidi.
5 Njẹ nisisiyi, Oluwa wipe, Kini mo
nṣe nihin, ti a kó awọn enia mi lọ lọfẹ?
awọn ti o jọba wọn mu nwọn kigbe, li
Oluwa wi; titi lojojumọ li a si nsọ̀rọ odì si
orukọ mi.
6 Nitorina awọn enia mi yio mọ̀ orukọ
mi li ọjọ na: nitori emi li ẹniti nsọrọ:
kiyesi i, emi ni.
7 Ẹsẹ ẹniti o mu ihinrere wá ti dara to
lori awọn oke, ti nkede alafia; ti nmu
ihìn rere ohun rere wá, ti nkede igbala;
ti o wi fun Sioni pe, Ọlọrun rẹ̀ njọba!
8 Awọn alóre rẹ yio gbe ohùn soke;
nwọn o jumọ fi ohùn kọrin: nitori nwọn
o ri li ojukoju, nigbati Oluwa ba mu Sioni
pada.
9 Bú si ayọ̀, ẹ jumọ kọrin, ẹnyin ibi
ahoro Jerusalemu: nitori Oluwa ti tù
awọn enia rẹ̀ ninu, o ti rà Jerusalemu pada.
10 Oluwa ti fi apá mimọ́ rẹ̀ hàn li oju
gbogbo awọn orilẹ-ède; gbogbo opin aiye
yio si ri igbala Ọlọrun wa.
11 Ẹ fà sẹhin, ẹ fà sẹhin, ẹ jade kuro
lãrin rẹ̀; ẹ má fọwọ kàn ohun aimọ́ kan:
ẹ kuro lãrin rẹ̀, ẹ jẹ mimọ́, ẹnyin ti ngbe
ohun-èlo Oluwa.
12 Nitori ẹ kì yio yara jade, bẹ̃ni ẹ kì
yio fi isare lọ; nitori Oluwa yio ṣãju nyin;
Ọlọrun Israeli yio si kó nyin jọ.
13 Kiyesi i, iranṣẹ mi yio fi oye bá ni
lò; a o gbe e ga, a o si gbe e leke, on o
si ga gidigidi.
14 Gẹgẹ bi ẹnu rẹ ti yà ọ̀pọlọpọ enia,
a bà oju rẹ̀ jẹ ju ti ẹnikẹni lọ, ati irisi rẹ̀
ju ti ọmọ enia lọ.
15 Bẹ̃ni yio buwọ́n ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède;
awọn ọba yio pa ẹnu wọn mọ si i, nitori
eyi ti a kò ti sọ fun wọn ni nwọn o ri; ati
eyi ti nwọn kò ti gbọ́ ni nwọn o rò.

ORI 53.

TALI o ti gbà ihìn wa gbọ́? tali a si ti
fi apá Oluwa hàn fun?
2 Nitori yio dàgba niwaju rẹ̀ bi ọ̀jẹlẹ
ohun ọ̀gbin, ati bi gbòngbo lati inu ilẹ
gbigbẹ: irísi rẹ̀ kò dara, bẹ̃ni kò li ẹwà,
nigbati a ba si ri i, kò li ẹwà ti a ba fi fẹ ẹ.
3 A kẹgan rẹ̀ a si kọ̀ ọ lọdọ awọn enia,
ẹni-ikãnu, ti o si mọ̀ ibanujẹ: o si dabi
ẹnipe o mu ki a pa oju wa mọ kuro lara
rẹ̀; a kẹgàn rẹ̀, awa kò si kà a si.
4 Lõtọ o ti ru ibinujẹ wa, o si gbe ikãnu
wa lọ; ṣugbọn awa kà a si bi ẹniti a nà,
ti a lù lati ọdọ Ọlọrun, ti a si pọ́n loju.
5 Ṣugbọn a ṣá a li ọgbẹ nitori irekọja
wa, a pa a li ara nitori aiṣedede wa; ìna
alafia wa wà lara rẹ̀, ati nipa ìna rẹ̀ li a
fi mu wa lara da.
6 Gbogbo wa ti ṣina kirikiri bi agutan,
olukuluku wa tẹ̀le ọ̀na ara rẹ̀; Oluwa si ti
mu aiṣedede wa gbogbo pade lara rẹ̀.
7 A jẹ ẹ ni iyà, a si pọ́n ọ loju, ṣugbọn
on kò yà ẹnu rẹ̀: a mu u wá bi ọdọ-agutan
fun pipa, ati bi agutan ti o yadi niwaju
olurẹrun rẹ̀, bẹ̃ni kò yà ẹnu rẹ̀.
8 A mu u jade lati ibi ihamọ on idajọ:
tani o si sọ iran rẹ̀? nitori a ti ke e kuro
ni ilẹ alãye: nitori irekọja awọn enia mi
li a ṣe lù u.
9 O si ṣe iboji rẹ̀ pẹlu awọn enia buburu,
ati pẹlu ọlọrọ̀ ni ikú rẹ̀; nitori kò hù
iwà-ipa, bẹ̃ni kò si arekereke li ẹnu rẹ̀.
10 Ṣugbọn o wu Oluwa lati pa a lara,
o ti fi i sinu ibanujẹ; nigbati iwọ o fi ẹmi
rẹ̀ ṣẹbọ fun ẹ̀ṣẹ: yio ri iru-ọmọ rẹ̀, yio mu
ọjọ rẹ̀ gùn, ifẹ Oluwa yio ṣẹ li ọwọ́ rẹ̀.
11 Yio ri ninu eso lãlã ọkàn rẹ̀, yio si
tẹ́ ẹ li ọrùn: nipa imọ̀ rẹ̀ ni iranṣẹ mi
olododo yio da ọ̀pọlọpọ lare; nitori yio rù
aiṣedede wọn wọnni.

Digitized by Google

12 Nitorina emi o fun u ni ipín pẹlu awọn ẹni-nla, yio si ba awọn alagbara pín ikogun, nitori o ti tú ẹmi rẹ̀ jade si ikú; a si kà a mọ awọn alarekọja, o si rù ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ; o si nṣipẹ̀ fun awọn alarekọja.

## ORI 54.

KỌRIN, iwọ àgan, ti kò bi ri; bú si orin, si ké rara, iwọ ti kò rọbi ri; nitori awọn ọmọ ẹni-alahoro pọ̀ ju awọn ọmọ ẹniti a gbe ni iyawo: li Oluwa wi.

2 Sọ ibi agọ rẹ di gbigbõro, si jẹ ki wọn nà aṣọ tita ibugbe rẹ jade: máṣe dási, sọ okùn rẹ di gigùn, ki o si mu ẽkàn rẹ le.

3 Nitori iwọ o ya si apa ọtún ati si apa osì, iru-ọmọ rẹ yio si jogun awọn Keferi: nwọn o si mu ki awọn ilu ahoro wọuni di ibi gbigbe.

4 Má bẹ̀ru, nitori oju kì yio tì ọ: bẹ̃ni ki o máṣe dãmu; nitori a ki yio doju tì ọ; nitori iwọ o gbagbe itìju igbà ewe rẹ, iwọ kì yio sì ranti ẹ̀gan iwà-opo rẹ mọ.

5 Nitori Ẹlẹda rẹ li ọkọ rẹ; Oluwa awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀; ati Olurapada rẹ Ẹni-Mimọ Israeli; Ọlọrun agbaiye li a o ma pè e.

6 Nitori Oluwa ti pè ọ bi obirin ti a kọ̀ silẹ, ti a si bà ni inu jẹ, ati bi aya igba ewe nigbati a ti kọ̀ ọ, li Ọlọrun rẹ wi.

7 Ni iṣẹju diẹ ni mo ti kọ̀ ọ silẹ, ṣugbọn li ãnu nla li emi o kó ọ jọ:

8 Ni ṣiṣàn ibinu li emi pa oju mi mọ kuro lara rẹ ni iṣẹju kan! ṣugbọn õre ainipẹkun li emi o fi ṣãnu fun ọ; li Oluwa Olurapada rẹ wi.

9 Nitori bi awọn omi Noa li eyi ri si mi, nitori gẹgẹ bi mo ti bura pe omi Noa kì yio bò aiye mọ, bẹ̃ni mo si ti bura pe emi kì yio binu si ọ, bẹ̃ni emi kì yio ba ọ wi.

10 Nitori awọn oke-nla yio ṣi lọ, a o si ṣi awọn oke kékèké ni idi, ṣugbọn ore mi kì yio fi ọ silẹ, bẹ̃ni emi kì yio ṣi majẹmu alafia mi ni ipò: li Oluwa wi, ti o ṣãnu fun ọ.

11 Iwọ ẹniti a npọ́n loju, ti a si nfi ijì gbákiri, ti a kò si tù ninu, wò o, emi o fi tìrõ tẹ́ okuta rẹ, emi o si fi safire fi ipilẹ rẹ le ilẹ.

12 Emi o fi rubi ṣe ṣonṣo-ile rẹ, emi o si fi okuta didán ṣe àsẹ rẹ; emi o si fi awọn okuta àṣayan ṣe agbègbe rẹ.

13 A o si kọ gbogbo awọn ọmọ rẹ lati ọdọ Oluwa wá; alafia awọn ọmọ rẹ yio si pọ̀.

14 Ninu ododo li a o fi idi rẹ mulẹ: iwọ o jina si inira; nitori iwọ kì yio bẹ̀ru: ati si ifoiya, nitori kì yio sunmọ ọ.

15 Kiye si i, ni kikojọ nwọn o kó ara wọn jọ, ṣugbọn ki iṣe nipasẹ mi; ẹnikẹni ti o ba wà lọ̀dọ rẹ yio ṣe ni tirẹ.

16 Kiye si i, emi li ẹniti o ti dá alagbẹ̀dẹ ti nfẹ́ iná ẹyín, ti o si mu ohunelò jade fun iṣẹ rẹ̀; emi li o si ti dá apanirun lati panirun.

17 Kò si ohun-ijà ti a ṣe si ọ ti yio lè ṣe nkan; ati gbogbo ahọn ti o dide si ọ ni idajọ ni iwọ o da li ẹbi. Eyi ni ogún awọn iranṣẹ Oluwa, lati ọdọ mi ni ododo wọn ti wá, li Oluwa wi.

## ORI 55.

NJẸ gbogbo ẹniti ongbẹ ngbẹ, ẹ wá sibi omi, ati ẹniti kò li owo; ẹ wá, ẹ rà, ki ẹ si jẹ; lõtọ, ẹ wá, ẹ rà ọti-waini ati wàra, laini owo ati laidiyele.

2 Nitori kini ẹ ṣe nná owo fun eyiti kì iṣe onjẹ? ati lãla nyin fun eyi ti kì itẹnilọrun? ni gbigbọ́, ẹ gbọ́ t'emi, ki ẹ si jẹ eyi ti o dara, si jẹ ki inu nyin dùn ninu ọra.

3 Ẹ tẹtilelẹ, ki ẹ si wá sọdọ mi: ẹ gbọ́, ọkàn nyin yio si yè: emi o si ba nyin dá majẹmu ainipẹkun, ãnu Dafidi ti o daju.

4 Kiye si i, emi ti fi on fun awọn enia fun ẹlẹri, olori ati alaṣẹ fun awọn enia.

5 Kiyesi i, iwọ o pe orilẹ-ède ti iwọ kò mọ̀, ati orilẹ-ède ti kò mọ̀ ọ yio sare wá sọdọ rẹ, nitori Oluwa Ọlọrun rẹ, ati nitori Ẹni-Mimọ Israeli; nitori on ti ṣe ọ li ogo.

6 Ẹ wá Oluwa nigbati ẹ le ri i, ẹ pè e, nigbati o wà nitosí.

7 Jẹ ki enia buburu kọ̀ ọ̀na rẹ̀ silẹ, ki ẹ̀lẹṣẹ si kọ̀ ironu rẹ̀ silẹ: si jẹ ki o yipada si Oluwa, on o si ṣãnu fun u, ati si Ọlọrun wa, yio si fi jì lọpọlọpọ.

8 Nitori èro mi kì iṣe èro nyin, bẹ̃ni ọ̀na nyin kì iṣe ọ̀na mi, li Oluwa wi.

9 Nitori bi ọrun ti ga ju aiye lọ, bẹ̃ni ọ̀na mi ga ju ọ̀na nyin lọ, ati èro mi ju èro nyin lọ.

10 Nitori gẹgẹ bi òjo ati ojo-didì iti ọrun wá ilẹ, ti kì isi tun pada sọhun, ṣugbọn ti o nrin ilẹ, ti o si nmu nkan hù jade ki o si rudi, ki o le fi irú fun awọn afọnrugbin, ati onjẹ fun ọjẹun:

11 Bẹ̃ni ọ̀rọ mi ti o ti ẹnu mi jade yio ri: kì yio pada sọdọ mi lofo, ṣugbọn yio ṣe eyiti o wù mi, yio si ma ṣe rere ninu ohun ti mo rán a.

12 Nitori ayọ̀ li ẹ o fi jade, alafia li a o fi tọ̀ nyin: awọn oke-nla ati awọn oke

Digitized by Google

kékèké yio bú si orin niwaju nyin, gbogbo
igi igbẹ yio si ṣapẹ́.
13 Igi firi yio hù jade dipò ẹgún, igi
mirtili yio hù jade dipò oṣuṣu: yio si jẹ
orukọ fun Oluwa, fun àmi aiyeraiye, ti a
kì yio ke kuro.

## ORI 56.

BAYI li Oluwa wi, Ẹ pa idajọ mọ, ẹ si
ṣe ododo: nitori igbala mi fẹrẹ idé,
ati ododo mi lati fi hàn.
2 Alabukun ni fun ọkọnrin na ti o ṣe
eyi, ati fun ọmọ enia ti o dì i mu: ti o pa
ọjọ isimi mọ laisọ ọ di aimọ́; ti o si pa
ọwọ́ rẹ̀ mọ kuro ni ṣiṣe ibi.
3 Ti kò si jẹ ki ọmọ alejò ti o ti dà ara
rẹ̀ pọ̀ mọ́ Oluwa sọ, wipe; Oluwa ti yà mi
kuro ninu awọn enia rẹ̀ patapata: bẹ̃ni kò
jẹ ki ìwẹfa wipe, Wò o, igi gbigbẹ ni mi.
4 Nitori bayi li Oluwa wi fun awọn
ìwẹfa ti nwọn pa ọjọ isimi mi mọ, ti nwọn
si yàn eyi ti o wù mi, ti nwọn si di majẹmu
mi mu;
5 Pe, emi o fi ipò kan fun wọn ni ile
mi, ati ninu odi mi, ati orukọ ti o dara jù
ti awọn ọmọ-ọkọnrin ati ọmọ-obirin lọ:
emi o fi orukọ ainipẹkun fun wọn, ti a kì
yio ke kuro.
6 Ati awọn ọmọ alejò ti nwọn dà ara
pọ̀ mọ Oluwa, lati sìn i, ati lati fẹ orukọ
Oluwa, lati jẹ iranṣẹ rẹ̀, olukuluku ẹniti o
pa ọjọ isimi mọ laisọ ọ di aimọ́, ti o si di
majẹmu mi mu;
7 Awọn li emi o si mu wá si oke-nla
mimọ́ mi, emi o si mu inu wọn dùn, ninu
ile adua mi: ẹbọ sisun wọn, ati irubọ wọn,
yio jẹ itẹwọgba lori pẹpẹ mi; nitori ile
adua li a o ma pe ile mi fun gbogbo enia.
8 Oluwa Jehofah, ẹniti o ṣà àtanu Israeli
jọ wipe, Emi o ṣà awọn ẹlomiran jọ sọdọ
rẹ̀, pẹlu awọn ti a ti ṣà jọ sọdọ rẹ̀.
9 Gbogbo ẹnyin ẹranko igbẹ, ẹ wá lati
pajẹ, ani gbogbo ẹranko igbẹ.
10 Afọju li awọn alore rẹ̀: òpe ni gbo-
gbo wọn, odi ajá ni nwọn, nwọn kò le igbó,
nwọn a ma sùn, nwọn ndubulẹ, nwọn fẹ
ma tõgbe.
11 Nitõtọ ọjẹun aja ni nwọn ti kì iyó,
ati oluṣọ́ agutan ti kò moye ni nwọn:
olukuluku wọn nwò ọ̀na ara wọn, oluku-
luku ntọju ere rẹ̀ lati ẹ̀kun rẹ̀ wá.
12 Ẹ wá, ni nwọn wi, emi o mu ọti-
waini wá, a o si mu ọti-lile li amuyo; ọla
yio si dabi ọjọ oni, yio si pọ̀ lọpọlọpọ.

## ORI 57.

OLODODO ṣegbe, kò si ẹniti o kà a si: a
mu awọn alãnu kuro, kò si ẹniti nrò
pe a mu olododo kuro ṣaju ibi.
2 On wọ̀ inu alafia: nwọn simi lori akete
wọn, olukuluku ẹniti nrin ninu iduroṣinṣin
rẹ̀.
3 Ṣugbọn ẹ sunmọ ihin, ẹnyin ọmọ oṣo,
iru-ọmọ panṣaga on àgbere.
4 Tani ẹnyin fi nṣe ẹsín? tani ẹnyin
nyanu gborò si, ti ẹnyin yọ ahọn jade si?
ọmọ alarekọja ki ẹnyin, iru-ọmọ eke,
5 Ti òriṣa ngùn labẹ gbogbo igi tutù, ti
ẹ npa awọn ọmọ wẹrẹ ninu afonifoji wọnni,
labẹ apáta ti o yanu?
6 Lãrin okuta ọ̀bọrọ́ odo ni ipín rẹ, awọn,
awọn ni ipín rẹ: ani awọn ni iwọ dà ẹbọ
ọrẹ mimu si: ti iwọ si rú ẹbọ ọrẹ jijẹ.
Emi ha le gbà itunu ninu wọnyi?
7 Lori oke giga-giga ni iwọ fi akete rẹ si,
ani nibẹ ni iwọ ti lọ lati rú ẹbọ.
8 Lẹhin ilẹkùn ati opó ilẹkun ni iwọ si
ti gbe iranti rẹ soke: nitori iwọ ti fi ara rẹ
hàn fun ẹlomiran dipò mi, iwọ si ti goke:
iwọ ti sọ akete rẹ di nla, iwọ si ba wọn dá
majẹmu; iwọ ti fẹ akete wọn nibiti iwọ
ri i.
9 Iwọ si ti lọ tiwọ ti ikunra sọdọ ọba,
iwọ si ti sọ õrùn didùn rẹ di pupọ, iwọ si ti
rán awọn ikọ̀ rẹ lọ jina réré, iwọ si ti rẹ̀
ara rẹ silẹ, ani si ipò okú.
10 Ãrẹ̀ mu ọ ninu jijìn ọ̀na rẹ: iwọ kò
wipe, Ireti kò si: ìye ọwọ́ rẹ ni iwọ ti ri;
nitorina ni inu rẹ kò ṣe bajẹ.
11 Ẹru tani mbà ọ ti o si nfòya, ti o
nṣeke, ti iwọ kò si ranti mi tabi ki o kà a
si? emi kò ha ti dakẹ ani lati igbãni wá,
iwọ kò si bẹ̀ru mi?
12 Emi o fi ododo rẹ, ati iṣẹ rẹ hàn;
nwọn kì o si gbè ọ.
13 Nigbati iwọ ba kigbe, jẹ ki awọn
ẹgbẹ rẹ ki o gbà ọ; ṣugbọn ẹfũfu ni yio gbá
gbogbo wọn lọ; ẽmi yio mu wọn kuro:
ṣugbọn ẹniti o ba gbẹkẹ rẹ̀ le mi yio ni ilẹ
na, yio si jogun oke mimọ́ mi.
14 On o si wipe, Ẹ kọ bèbe, ẹ kọ bèbe, ẹ
tun ọ̀na ṣe; ẹ mu ìdugbolu kuro li ọ̀na
awọn enia mi.
15 Nitori bayi li Ẹni-giga, ati ẹniti
agbega soke sọ, ti ngbe aiyeraiye, orukọ
ẹniti ijẹ Mimọ́, emi ngbe ibi giga ati mimọ́,
ati inu ẹniti o li ẹmi irobinujẹ on irẹlẹ pẹlu,
lati mu ẹmi awọn onirẹlẹ sọji, ati lati mu
ọkàn awọn onirobinujẹ sọji.
16 Nitori emi kì yio jà titi lai, bẹ̃ni emi

Digitized by Google

kì yio binu nigbagbogbo: nitori ẹmi iba
daku niwaju mi, ati ẽmi ti emi ti dá.
17 Mo ti binu nitori aiṣedede ojukokoro
rẹ̀, mo si lù u: mo lumọ, mo si binu, on
si nlọ ni iṣina li ọ̀na ọkàn rẹ̀.
18 Mo ti ri ọ̀na rẹ̀, emi o si mu u li ara
da: emi o si tọ́ ọ pẹlu, emi o si mu itunu
pada fun u wá, ati fun awọn aṣọ̀fọ rẹ̀.
19 Emi li o da eso ète; Alafia, alafia
fun ẹniti o jina réré, ati fun ẹniti o wà ni-
tosí, ni Oluwa wi; emi o si mu u li ara
da.
20 Ṣugbọn awọn enia buburu dabi okun
ríru, nigbati kò le simi, eyiti omi rẹ̀ nsọ
ẹrẹ ati ẽri soke.
21 Alafia kò si fun awọn enia buburu,
ni Ọlọrun mi wi.

## ORI 58.

KE rara, máṣe dasi, gbe ohùn rẹ soke bi
ipè, ki o si fi irekọja awọn enia mi
hàn wọn, ati ile Jakobu, ẹ̀ṣẹ wọn.
2 Ṣugbọn nwọn nwá mi lojojumọ, nwọn
si ni inu didun lati mọ̀ ọ̀na mi, bi orilẹ-ède
ti nṣe ododo, ti kò si fi ilàna Ọlọrun wọn
silẹ: nwọn mbere ilàna ododo wọnnì lọwọ
mi; nwọn a ma ṣe inu didun ati sunmọ
Ọlọrun.
3 Nitori kini awa ṣe ngbãwẹ̀, ti iwọ kò
si ri i? nitori kini awa jẹ ọkàn wa ni ìya,
ti iwọ kò si mọ̀? Kiyesi i, li ọjọ ãwẹ̀ nyin
ẹnyin nṣe afẹ́, ẹ si nfi agbara mu ni ṣe gbo-
gbo iṣẹ nyin.
4 Kiyesi i, ẹnyin ngbãwẹ̀ fun ìja ati
agọn, ati lilù, nipa ikũku ìwa-buburu: ẹ
máṣe gbãwẹ bi ti ọjọ yi, ki a le gbọ́ ohùn
nyin li oke.
5 Ãwẹ̀ iru eyi ni mo yàn bi? ọjọ ti enia
njẹ ọkàn rẹ̀ ni ìya? lati tẹ ori rẹ̀ ba bi
koriko odo? ati lati tẹ́ aṣọ ọ̀fọ ati ẽru labẹ
rẹ̀? iwọ o ha pe eyi ni ãwẹ̀, ati ọjọ itẹwọ-
gba fun Oluwa?
6 Awẹ ti mo ti yàn kọ́ eyi? lati tú ọjá
aiṣododo, lati tú ẹrù wiwo, ati lati jẹ ki
anilara lọ lọfẹ, ati lati já gbogbo ajàga.
7 Kì ha ṣe lati fi onjẹ rẹ fun awọn ti ebi
npa, ati ki iwọ ki o mu awọn otòṣi ti a tì
sode wá si ile rẹ? nigbati iwọ ba ri arin-
hòho, ki iwọ ki o bò o, ki iwọ ki o má si fi
ara rẹ pamọ kuro lọdo ẹran-ara tirẹ.
8 Nigbana ni imọlẹ rẹ yio bẹ́ jade bi
owurọ, ilera rẹ yio sọ jade kánkán: ododo
rẹ yio si lọ ṣaju rẹ; ogo Oluwa yio kó ọ jọ.
9 Nigbana ni iwọ o pè, Oluwa yio si
dahun; iwọ o kigbe, on o si wipe, Emi nĩ.
Bi iwọ ba mu àjaga, ninà ika, ati sisọ asan,
kuro lãrin rẹ.
10 Bi iwọ ba fà ọkàn rẹ jade fun ẹniti
ebi npa, ti o si tẹ́ ọkàn ti a npọ́n loju
lọrùn, nigbana ni imọlẹ rẹ yio si là ninu
okùnkun, ati okùnkun rẹ bi ọ̀san gangan.
11 Oluwa yio ma tọ́ ọ nigbagbogbo, yio
si tẹ́ ọkàn rẹ lọrun ni ibi gbigbẹ, yio si mu
egungun rẹ sanra; iwọ o si dabi ọgbà ti a
bomirin, ati bi isun omi ti omi rẹ̀ kì itán.
12 Ati awọn tirẹ yio mọ ibi ahoro atijọ
wọnni: iwọ o gbé ipilẹ iran ọ̀pọlọpọ ró, a o
si ma pe ọ ni, Alatunṣe ẹyà ni, Olumupada
ọ̀na wọnni lati gbe inu rẹ̀.
13 Bi iwọ ba yi ẹsẹ rẹ kuro li ọjọ isimi,
lati má ṣe afẹ́ rẹ li ọjọ isimi mi; ti iwọ si
pè ọjọ isimi ni adùn, ọjọ mimọ́ Oluwa,
ọlọ̀wọ; ti iwọ si bọ̀wọ fun u, ti iwọ kò hù
ìwa rẹ, tabi tẹle afẹ rẹ, tabi sọ ọ̀rọ ara rẹ.
14 Nigbana ni inu rẹ yio dùn si Oluwa,
emi o si mu ọ gùn ibi giga aiye, emi o si fi
ilẹ níni Jakobu baba rẹ bọ́ ọ: nitori ẹnu
Oluwa li o ti sọ ọ.

## ORI 59.

KIYESI i, ọwọ́ Oluwa kò kuru lati gbàni,
bẽni eti rẹ̀ kò wuwo ti kì yio fi gbọ́.
2 Ṣugbọn aiṣedede nyin li o yà nyin
kuro lọdọ Ọlọrun nyin, ati ẹ̀ṣẹ nyin li o pa
oju rẹ̀ mọ kuro lọdọ nyin, ti on kì yio fi
gbọ́.
3 Nitori ọwọ́ nyin di alaimọ́ fun ẹ̀jẹ, ati
ika nyin fun aiṣedede, ète nyin nsọ eke,
ahọn nyin nsọ ibi jade.
4 Kò si ẹniti nwá ẹtọ́, bẽni kò si ẹniti
ndajọ ni otitọ: nwọn gbẹkẹle ohun asan,
nwọn nsọ eke; nwọn loyun ikà, nwọn mbí
iparun.
5 Nwọn npa ẹyin pamọlẹ, nwọn nwun
okùn alantakùn: ẹniti o jẹ ninu ẹyin wọn
yio kú, ati eyi ti a tẹ̀ bẹ́ ọká jade.
6 Okùn wọn kì yio di ẹwù, bẽni nwọn
kì yio fi iṣẹ wọn bò ara wọn: iṣẹ wọn ni
iṣe ikà, iṣe ipá si mbẹ li owọ́ wọn.
7 Ẹsẹ wọn sare si ibi, nwọn si yara lati
tajẹ̀ alaiṣẹ̀ silẹ: èro wọn èro ibi ni; ibajẹ
ati iparun mbẹ ni ipa wọn.
8 Ọna alafia ni nwọn kò mọ̀; kó si idajọ
kan ninu ìrin wọn: nwọn ṣe ipa-ọ̀na wiwọ́
fun ara wọn: ẹnikẹni ti o ba tọ̀ ọ kì yio
mọ̀ alafia.
9 Nitori na ni idajọ jìna si wa, bẽni
ododo kì yio le wa bá, awa duro dè imọlẹ,
ṣugbọn kiyesi i, okunkun, a duro de imọlẹ,
ṣugbọn a nrin ninu okunkun.
10 A nwá ogiri kiri bi afọju, awa si nwá

Digitized by Google

ọ̀na bi ẹniti kò li oju: awa nkọsẹ lọsangan-
gan bi ẹnipe loru, ni ibi ahoro, bi okú.
11 Gbogbo wa mbu bi beari, awa si npo-
hunrere bi oriri: awa wò ọ̀na fun idajọ,
ṣugbọn kò si, fun igbala, ṣugbọn o jìna si
wa.
12 Nitori irekọja wa npọ̀ si i niwaju rẹ,
ẹ̀ṣẹ wa njẹri gbè wa, nitori irekọja wa mbẹ
lọdọ wa, niti aiṣedede wa, awa mọ̀ wọn.
13 Ni rirekọja ati ṣiṣeke si Oluwa, ifa-
ṣẹhin kuro lọdọ Ọlọrun wa, isọrọ inilara ati
ìṣọtẹ, liloyun ati sisọrọ eke lati inu jade wá.
14 A dá idajọ pada, ẹtọ́ si duro lokerè
rére: otitọ ṣubu ni igboro, aiṣègbe kò le
wọ ile.
15 Otitọ kò si, ẹniti o si kuro ninu ibi o
sọ ara rẹ̀ di ijẹ: Oluwa si ri i, o si buru
loju rẹ̀, ti idajọ kò si.
16 O si ri pe kò si ẹnikan, ẹnu si yà a
pe onipẹ̀ kò si, nitorina apá rẹ̀ mu igbala
fun u wá; ati ododo rẹ̀, on li o gbé e ró.
17 O si gbe ododo wọ̀ bi awo-aiya, o si fi
akoro irin igbala dé ara rẹ̀ lori: o wọ̀ ẹwù
igbẹsan li aṣọ, a si fi itara wọ̀ ọ bi agbada.
18 Gẹgẹ bi ere iṣe wọn, bẹ̃ gẹgẹ ni yio
san a fun wọn, irúnu fun awọn ọta rẹ̀,
igbẹsan fun awọn ọta rẹ̀; fun awọn erekuṣu
yio san ẹsan.
19 Nwọn o si bẹ̀ru orukọ Oluwa lati ìwọ-
õrùn wá, ati ogo rẹ̀ lati ilà-õrun wá. Ni-
gbati ọta yio de bi kikún omi, Ẹmi Oluwa
yio gbe ọpágun soke si i.
20 Olurapada yio si wá si Sioni, ati sọdọ
awọn ti o yipada kuro ninu irekọja ni Jako-
bu, ni Oluwa wi.
21 Niti emi, eyi ni majẹmu mi pẹlu wọn,
ni Oluwa wi; Ẹmi mi ti o wà lara rẹ̀, ati
ọ̀rọ mi ti mo fi si ẹnu rẹ, kì yio kuro li
ẹnu rẹ, tabi kuro lẹnu iru-ọmọ rẹ, tabi
kuro lẹnu iru-ọmọ ọmọ rẹ, ni Oluwa wi,
lati isisiyi lọ ati lailai.

## ORI 60.

DIDE, tàn imọlẹ: nitori imọlẹ rẹ dé, ogo
Oluwa si yọ lara rẹ.
2 Nitori kiyesi i, okùnkun bò aiye mọlẹ,
ati okùnkun biribiri bò awọn enia: ṣugbọn
Oluwa yio yọ lara rẹ, a o si ri ogo rẹ̀ lara
rẹ.
3 Awọn keferi yio wá si imọlẹ rẹ, ati
awọn ọba si titàn yiyọ rẹ.
4 Gbe oju rẹ soke yika, ki o si wò;
gbogbo wọn ṣa ara wọn jọ pọ̀, nwọn wá
sọdọ rẹ: awọn ọmọ rẹ ọkọnrin yio ti ọ̀na
jijin wá, a o si tọju awọn ọmọ rẹ obirin li
ẹgbẹ rẹ.
5 Nigbana ni iwọ o ri, oju rẹ o si mọ́lẹ,
ọkàn rẹ yio si yipada, yio si di nla: nitori
a o yi ọrọ̀ okun pada si ọ, ipá awọn Keferi
yio wá sọdọ rẹ.
6 Ọ̀pọlọpọ rakunmi yio bò ọ mọlẹ, awọn
ọmọ rakunmi Midiani on Ẹfa; gbogbo
wọn o wá lati Ṣeba: nwọn o mu wura ati
turari wá; nwọn o fi iyìn Oluwa hàn sode.
7 A o ṣà gbogbo ọwọ́-ẹran Kedari jọ sọdọ
rẹ, awọn àgbo Nebaioti yio ṣe iranṣẹ fun ọ;
nwọn o goke wá si pẹpẹ mi pẹlu itẹwọgba,
emi a si ṣe ile ogo mi li ogo.
8 Tani wọnyi ti nfò bi awọsanma, ati bi
awọn ẹiyẹle si ojule wọn?
9 Nitõtọ erekuṣu wọnni yio duro dè mi,
ọkọ Tarṣiṣi wọnni li ekini, lati mu awọn
ọmọ rẹ ọkọnrin ti ọ̀na jijin wá, fadaka wọn,
ati wura wọn pẹlu wọn, fun orukọ Oluwa
Ọlọrun rẹ, ati fun Ẹni-Mimọ́ Israeli, nito-
riti on ti ṣe ọ logo.
10 Awọn ọmọ alejo yio si mọ odi rẹ:
awọn ọba wọn yio ṣe iranṣẹ fun ọ: nitori
ni ikánnu mi ni mo lù ọ, ṣugbọn ni inu
rere mi ni mo si ṣãnu fun ọ.
11 Nitori na awon ãsẹ rẹ yio ṣi silẹ ni-
gbagbogbo; a kì yio se wọn lọsan tabi loru,
ki a le mu ọla awọn Keferi wá sọdọ rẹ, ki a
ba si mu awọn ọba wọn wá.
12 Nitori orilẹ-ède, tabi ilẹ ọba ti kì yio
sin ọ, yio ṣegbe; orilẹ-ède wọnni li a o sọ
wọn dahoro raurau.
13 Ogo Lebanoni yio wá sọdọ rẹ, igi firi,
igi pine, pẹlu igi boksi, lati ṣe ibi mimọ́
mi li ọṣọ; emi o ṣe ibi ẹsẹ mi logo.
14 Awọn ọmọkọnrin awọn aninilara rẹ
pẹlu yio wá ni itẹriba sọdọ rẹ; gbogbo
awọn ti o ti ngàn ọ, nwọn o tẹ̀ ara wọn ba
silẹ li atẹlẹsẹ rẹ, nwọn o si pe ọ ni Ilu Olu-
wa, Sioni ti Ẹni-Mimọ́ Israeli.
15 Ni bi a ti kọ̀ ọ silẹ, ti a si ti korira
rẹ, tobẹ̃ ti ẹnikan kò kọja lãrin rẹ, emi o
sọ ọ́ di ogo aiyeraiye, ayọ̀ iran-de-iran
ọ̀pọlọpọ.
16 Iwọ o mu wàra awọn Keferi, iwọ o si
mu ọmu awọn ọba; iwọ o si mọ̀ pe, emi
Oluwa ni Olugbala rẹ, ati Olurapada rẹ,
Ẹni-alagbara Jakobu.
17 Nipo idẹ emi o mu wura wá, nipo
irin emi o mu fadaka wá, ati nipo igi, idẹ,
ati nipo okuta, irin: emi o ṣe awọn ijoye
rẹ ni alafia, ati awọn akọniṣiṣẹ rẹ ni ododo.
18 A kì yio gbọ́ ìwa-ipá mọ ni ilẹ rẹ,
idahoro tabi iparun li agbègbe rẹ; ṣugbọn
iwọ o pe odi rẹ ni Igbala, ati ãsẹ rẹ ni Iyin.
19 Õrùn kì yio jẹ imọlẹ rẹ mọ li ọsan,
bẹ̃ni oṣupa kì yio fi imọlẹ rẹ̀ ràn fun ọ;

Digitized by Google

ṣugbọn Oluwa yio ṣe imọlẹ ainipẹkun rẹ, ati Ọlọrun rẹ ogo rẹ.

20 Orùn rẹ ki yio wọ̀ mọ; bẽni oṣupa rẹ kì yio wọ̀kùn: nitori Oluwa yio jẹ imọlẹ ainipẹkun fun ọ, ọjọ ãwẹ̀ rẹ wọnni yio si de opin.

21 Ati awọn enia rẹ, gbogbo wọn o jẹ olododo: nwọn o jogun ilẹ na titi lailai, ẹka gbigbin mi, iṣẹ ọwọ́ mi, ki a ba le yìn mi logo.

22 Ẹni-kekere kan ni yio di ẹgbẹrun, ati kekere kan di alagbara orilẹ-ède: emi Oluwa yio ṣe e kankan li akokò rẹ̀.

## ORI 61.

EMI Oluwa Jehofah mbẹ lara mi: nitori o ti fi ami ororo yàn mi lati wãsu ihin-rere fun awọn òtoṣi; o ti rán mi lati ṣe awotán awọn onirobinujẹ ọkàn, lati kede idasilẹ fun awọn igbekùn, ati iṣisilẹ tubu fun awọn ondè.

2 Lati kede ọdun itẹwọgba Oluwa, ati ọjọ ẹsan Ọlọrun wa; lati tù gbogbo awọn ti ngbãwẹ̀ ninu.

3 Lati yàn fun awọn ti nṣọ̀fọ fun Sioni, lati fi ọṣọ́ fun wọn nipo ẽrú, ororo ayọ̀ nipo ọ̀fọ, aṣọ iyìn nipo ẹmi ibanujẹ, ki a le pè wọn ni igi ododo, ọgbìn Oluwa, ki a le yìn i logo.

4 Nwọn o si mọ ibi ahoro atijọ wọnni, nwọn o gbe ahoro atijọ wọnni ro, nwọn o si tun ilu wọnni ti o ṣofo ṣe, ahoro iran ọ̀pọlọpọ.

5 Awọn alejo yio si duro, nwọn o si bọ́ ọwọ́ ẹran nyin, awọn ọmọ alejò yio si ṣe atulẹ nyin, ati olurẹ́ ọwọ́ àjara nyin.

6 Ṣugbọn a o ma pè nyin ni Alufa Oluwa: nwọn o ma pè nyin ni Iranṣẹ Ọlọrun wa: ẹ o jẹ ọrọ̀ awọn Keferi, ati ninu ogo wọn li ẹ o ma ṣogo.

7 Nipo itiju nyin ẹ o ni iṣẹpo-meji, ati nipo idãmu, nwọn o yọ̀ ninu ipin wọn: nitorina nwọn o ni iṣẹpo-meji ni ilẹ wọn; ayọ̀ ainipẹkun yio jẹ ti wọn.

8 Nitori emi Oluwa fẹ idajọ, mo korira ijale ninu aiṣododo; emi o si fi iṣẹ wọn fun wọn ni otitọ, emi o si ba wọn da majẹmu aiyeraiye.

9 A o si mọ̀ iru wọn ninu awọn Keferi, ati iru-ọmọ wọn lãrin awọn enia gbogbo, ẹniti o ri wọn yio mọ̀ wọn, pe, iru-ọmọ ti Oluwa busi ni nwọn.

10 Emi o yọ̀ gidigidi ninu Oluwa, ọkàn mi yio yọ̀ ninu Ọlọrun mi; nitori o ti fi agbáda wọ̀ mi, o ti fi aṣọ ododo bò mi, gẹgẹ bi ọkọ iyawó ti iṣe ara rẹ̀ lọṣọ́, ati bi iyawó ti ĩfi ohun ọṣọ́ ṣe ara rẹ̀ lọṣọ́.

11 Nitori gẹgẹ bi ilẹ ti imu ẽhù rẹ̀ jade, ati bi ọgbà ti imu ohun ti a gbìn sinu rẹ̀ hù soke; bẽni Oluwa Jehofah yio mu ododo ati iyìn hù soke niwaju gbogbo orilẹ-ede.

## ORI 62.

NITORI ti Sioni emi kì yio dakẹ, ati nitori ti Jerusalemu emi kì yio simi, titi ododo rẹ̀ yio fi jade bi titan imọlẹ, ati igbala rẹ̀ bi fitila ti njó.

2 Ati awọn keferi yio ri ododo rẹ, ati gbogbo ọba yio ri ogo rẹ: a o si fi orukọ titun pè ọ, eyiti ẹnu Oluwa yio darukọ.

3 Iwọ o jẹ ade ogo pẹlu li ọwọ́ Oluwa, ati lawani ọba li ọwọ́ Ọlọrun rẹ.

4 A ki yio pè ọ ni Ikọ̀silẹ mọ, bẽni a ki yio pè ilẹ rẹ ni Ahoro mọ: ṣugbọn a o pè ọ ni Hefsiba: ati ilẹ rẹ ni Beula: nitori inu Oluwa dùn si ọ, a o si gbe ilẹ rẹ ni iyawo.

5 Gẹgẹ bi ọdọmọkọnrin ti igbé wundia ni iyawo, bẽni awọn ọmọ rẹ ọkọnrin yio gbe ọ ni iyawo: ati bi ọkọ iyawo ti iyọ̀ si iyawo, bẽni Ọlọrun rẹ yio yọ̀ si ọ.

6 Emi ti fi awọn alore sori odi rẹ, iwọ Jerusalemu, ti kì yio pa ẹnu wọn mọ lọsan ati loru titilai: ẹnyin ti nṣe iranti Oluwa, ẹ máṣe dakẹ.

7 Ẹ máṣe fun u ni isimi, titi yio fi fi idi Jerusalemu mulẹ, ti yio ṣe e ni iyìn li aiye.

8 Oluwa ti fi apá ọtun rẹ̀, ati apá agbara rẹ̀ bura, Lõtọ emi kì yio fi ọ̀ka rẹ ṣe onjẹ fun awọn ọta rẹ mọ, bẽni awọn ọmọ ajeji kì yio mu ọti-waini rẹ, eyi ti iwọ ti ṣiṣẹ fun.

9 Ṣugbọn awọn ti o ṣà a jọ yio jẹ ẹ, nwọn o si yìn Oluwa; ati awọn ti nkó o jọ yio mu u, ninu ãfin mimọ́ mi.

10 Ẹ kọja lọ, ẹ kọja li ẹnu bode; tun ọ̀na awọn enia ṣe; kọ bèbe, kọ bèbe opopo; ṣà okuta wọnni kuro, gbe ọpagun ró fun awọn enia.

11 Kiyesi i, Oluwa ti kede titi de opin aiye: Ẹ wi fun ọmọbirin Sioni pe, Wo o, igbala rẹ de; wo o, ère rẹ̀ wà pẹlu rẹ̀, ati ẹsan rẹ̀ niwaju rẹ̀.

12 A o si ma pè wọn ni, Enia mimọ́, Ẹni-irapada Oluwa: a o si ma pè ọ ni, Iwári, Ilu aikọ̀silẹ.

## ORI 63.

TANI eleyi ti o ti Edomu wá, ti on ti aṣọ arẹpọ́n lati Bosra wá? eyi ti o li ogo

Digitized by Google

ninu aṣọ rẹ̀, ti o nyan ninu titobi agbara
rẹ̀? Emi ni ẹniti nsọ̀rọ li odôdo, ti o ni
ipá lati gbala.
2 Nitori kini aṣọ rẹ fi pọ́n, ti aṣọ rẹ
wọnni fi dabi ẹniti ntẹ̀ ohun-èlo ifunti
waini?
3 Emi nikan ti tẹ̀ ohun-elò ifunti waini;
ati ninu awọn enia, ẹnikan kò pẹlu mi:
nitori emi tẹ̀ wọn ninu ibinu mi, mo si tẹ̀
wọn mọlẹ ninu irúnu mi; ẹ̀jẹ wọn si ta si
aṣọ mi, mo si ṣe gbogbo ẹ̀wu mi ni abawọ́n.
4 Nitori ọjọ ẹsan mbẹ li aiya mi, ọdun
awọn ẹni-irapada mi ti de.
5 Mo si wò, kò si si oluranlọwọ; ẹnu si
yà mi pe kò si olugbéro; nitorina apa ti
emi tikalami mu igbala wá sọdọ mi; ati
irúnu mi, on li o gbe mi ro.
6 Emi si tẹ̀ awọn enia mọlẹ ninu ibinu
mi, mo si mu wọn mu yó ninu irúnu mi,
mo si mu ipa wọn sọkalẹ si ilẹ.
7 Emi o sọ ti iṣeun ifẹ Oluwa, iyìn Oluwa
gẹgẹ bi gbogbo eyiti Oluwa ti fi fun wa,
ati ti ore nla si ile Israeli, ti o ti fi fun wọn
gẹgẹ bi ãnu rẹ̀, ati gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ iṣeun
ifẹ rẹ̀.
8 On si wipe, Lõtọ enia mi ni nwọn,
awọn ọmọ ti kì iṣeke: on si di Olugbala
wọn.
9 Ninu gbogbo ipọnju wọn, oju a pọn ọ,
angeli iwaju rẹ̀ si gbà wọn: ninu ifẹ rẹ̀ ati
suru rẹ̀ li o rà wọn pada; o si gbe wọn, o
si rù wọn ni gbogbo ọjọ igbani.
10 Ṣugbọn nwọn ṣọtẹ, nwọn si bi Ẹmi
mimọ́ rẹ̀ ninu; nitorina li o ṣe pada di ọta
wọn, on tikalarẹ̀ si ba wọn ja.
11 Nigbana ni o ranti ọjọ atijọ, Mose,
awọn enia rẹ̀, wipe, Nibo li ẹniti o mu wọn
ti inu okun jade gbe wà, ti on ti olùṣọ
agutan ọwọ́-ẹran rẹ̀? nibo li ẹniti o fi Ẹmi
mimọ́ rẹ̀ sinu rẹ̀ gbe wà?
12 Ti o fi ọwọ́ ọtun Mose dà wọn, pẹlu
apá rẹ̀ ti o logo, ti o npin omi meji niwaju
wọn, lati ṣe orukọ aiyeraiye fun ara rẹ̀?
13 Ti o mu wọn là ibú ja, bi ẹṣin li
aginjù, ki nwọn ki o má ba kọsẹ?
14 Gẹgẹ bi ẹran ti isọ̀kalẹ lọ si afonifoji,
bẹ̃ni Ẹmi Oluwa mu u simi: bẹ̃ni iwọ tọ́
awọn enia rẹ, lati ṣe orukọ ti o li ogo fun
ara rẹ.
15 Wò ilẹ lati ọrun wá, ki o si kiyesi
lati ibugbe iwa mimọ́ rẹ ati ogo rẹ wá:
nibo ni itara rẹ ati agbara rẹ, ọ̀pọlọpọ
iyanu rẹ, ati ãnu rẹ sọdọ mi gbe wà? a ha
da wọn duro bi?
16 Laiṣiyemeji iwọ ni baba wa, bi Abra-
hamu tilẹ ṣe alaimọ̀ wa, ti Israeli kò si
jẹwọ wa: iwọ Oluwa, ni baba wa, Olura-
pada wa; lati aiyeraiye ni orukọ rẹ.
17 Oluwa, nitori kili o ṣe mu wa ṣina
kuro li ọ̀na rẹ, ti o si sọ ọkàn wa di lile
kuro ninu ẹ̀ru rẹ? Yipada nitori awọn
iranṣẹ rẹ, awọn ẹya ilẹnini rẹ.
18 Awọn enia mimọ́ rẹ ti ni i, ni igba
diẹ: awọn ọta wa ti tẹ̀ ibi mimọ́ rẹ mọlẹ.
19 Tirẹ li awa: lati lailai iwọ kò jọba
lori wọn, a kò pè orukọ rẹ mọ wọn.

## ORI 64.

IWỌ iba jẹ fà awọn ọrun ya, ki iwọ si
sọkalẹ, ki awọn oke-nla ki o le yọ́ ni-
waju rẹ.
2 Gẹgẹ bi igbati iná ileru ti njọ, bi iná
ti imu omi hó, lati sọ orukọ rẹ di mimọ̀
fun awọn ọta rẹ, ki awọn orilẹ-ède ki o le
warìri niwaju rẹ!
3 Nigbati iwọ ṣe nkan wọnni ti o lẹ̀ru ti
awa kò fi oju sọna fun, iwọ sọkalẹ wá, awọn
oke-nla yọ́ niwaju rẹ.
4 Nitori lati ipilẹṣẹ aiye wá, a kò ti
igbọ́, bẹ̃ni eti kò ti igbọ́ finrin, bẹ̃ni oju kò
ti iri Ọlọrun kan lẹhin rẹ, ti o ti pèse fun
ẹniti o duro dè e.
5 Iwọ pade ẹniti nyọ̀ ti o nṣiṣẹ ododo, ti
o ranti rẹ li ọ̀na rẹ: kiyesi i, iwọ binu;
nitori awa ti dẹṣẹ; a si pẹ ninu wọn, a o
ha si là?
6 Gbogbo wa si dabi ohun aimọ́, gbogbo
ododo wa si dabi akisa ẹlẹgbin; gbogbo
wa si rẹ̀ bi ewe; aiṣedede wa si mu wa
kuro bi afẹfẹ.
7 Kò si ẹniti npè orukọ rẹ, ti o si rú ara
rẹ̀ soke lati di ọ mu: nitori iwọ ti pa oju
rẹ mọ kuro lara wa, iwọ si ti run wa, nitori
aiṣedede wa.
8 Ṣugbọn nisisiyi, Oluwa, iwọ ni baba
wa; awa ni amọ̀, iwọ si ni ọmọ; gbogbo
wa si ni iṣẹ ọwọ́ rẹ.
9 Máṣe binu kọja àla, Oluwa, ki o má
si ranti aiṣedede wa titilai: kiyesi i, wò,
awa bẹ̀ ọ, enia rẹ ni gbogbo wa iṣe.
10 Awọn ilu mimọ́ rẹ di aginju, Sioni di
aginju, Jerusalemu di ahoro.
11 Ile wa mimọ́ ati ologo, nibiti awọn
baba wa ti nyìn ọ, li a fi iná kun: gbogbo
ohun ãyo wa si ti run.
12 Iwọ o ha da ara rẹ duro nitori nkan
wọnyi, Oluwa? iwọ o ha dakẹ, ki o si pọn
wa loju kọja àla?

## ORI 65.

A WÁ mi lọdọ awọn ti kò bere mi; a ri
mi lọdọ awọn ti kò wá mi: mo wi

Digitized by Google

fun orilẹ-ède ti a kò pe li orukọ mi pe, Wò
mi, wò mi.
2 Ni gbogbo ọjọ ni mo ti nà ọwọ́ mi si
awọn ọlọtẹ̀ enia, ti nrìn li ọ̀na ti kò dara,
nipa ìro ara wọn ;
3 Awọn enia ti o nṣọ̀ mi ni inu nigba-
gbogbo kàn mi loju ; ti nrubọ ninu agbàla,
ti nwọn si nfi turari jona lori pẹpẹ briki.
4 Awọn ti ngbe inu ibojì, ti nwọn si
nwọ̀ ni ile awọn oriṣa, ti njẹ ẹran ẹlẹdẹ,
agbòro nkan irira si mbẹ ninu ohun-elò
wọn ;
5 Ẹniti o wipe, Duro fun ara rẹ, máṣe
sunmọ mi ; nitori ti mo ṣe mimọ́ jù ọ lọ.
Wọnyi li ẽfin ni imu mi, iná ti njo ni gbo-
gbo ọjọ ni.
6 Kiyesi i, ati kọwe rẹ̀ niwaju mi : emi
kì o dakẹ, ṣugbọn emi o gbẹ̀san, ani ẹ̀san
si aiya wọn,
7 Aiṣedede nyin, ati aiṣedede awọn baba
nyin ṣọkan pọ̀, li Oluwa wi, awọn ẹniti o fi
turari jona lori oke-nla, ti nwọn mbu ọla
mi kù lori awọn oke kékèké : nitori na li
emi o wọ̀n iṣẹ wọn iṣaju, sinu aiya wọn.
8 Bayi ni Oluwa wi, gẹgẹ bi a ti iri ọti-
waini titun ninu ìdi eso àjara, ti a si nwipe,
Máṣe bà a jẹ nitori ibukun mbẹ ninu rẹ̀ :
bẽli emi o ṣe nitori awọn iranṣẹ mi, ki emi
ki o má ba pa gbogbo wọn run.
9 Emi o si mu iru kan jade ni Jakobu,
ati ajogun oke-nla mi lati inu Juda : ayan-
fẹ mi yio si jogun rẹ̀, awọn iranṣẹ mi yio
si gbe ibẹ.
10 Ṣaroni yio di agbo-ẹran, ati afonifoji
Akori ibikan fun awọn ọwọ́ ẹran lati du-
bulẹ ninu rẹ̀, nitori awọn enia mi ti o ti wá
mi kiri.
11 Ṣugbọn ẹnyin ti o kọ̀ Oluwa silẹ, ti o
gbàgbe oke-nla mimọ́ mi, ti o pèse tabili
fun Gadi, ti o si fi ọrẹ mimu kun Meni.
12 Nitorina li emi o ṣe kà nyin fun idà,
gbogbo nyin yio wolẹ fun pipa : nitori
nigbati mo pè, ẹnyin kò dahùn ; nigbati
mo sọ̀rọ, ẹnyin kò gbọ́ ; ṣugbọn ẹnyin ṣe
ibi loju mi, ẹnyin si yàn eyiti inu mi kò
dùn si.
13 Nitorina bayi ni Oluwa Jehofah wi,
Kiyesi i awọn iranṣẹ mi o jẹun, ṣugbọn ebi
yio pa ẹnyin : kiyesi i, awọn iranṣẹ mi o
mu, ṣugbọn ongbẹ o gbẹ ẹnyin : kiyesi i,
awọn iranṣẹ mi o yọ̀ ṣugbọn oju o tì ẹnyin :
14 Kiyesi i, awọn iranṣẹ mi yio kọrin
fun inudidun, ṣugbọn ẹnyin o ke fun iban-
ujẹ ọkàn, ẹnyin o si hu fun irobinujẹ
ọkàn.
15 Ẹnyin o si fi orukọ nyin silẹ fun egún
fun awọn ayanfẹ mi : nitori Oluwa Jehofah
yio pa ọ, yio si pè awọn iranṣẹ rẹ̀ li orukọ
miran :
16 Ki ẹniti o fi ibukun fun ara rẹ̀ li
aiye, ki o fi ibukun fun ara rẹ̀ ninu Ọlọ-
run otitọ ; ẹniti o si mbura li aiye ki o fi
Ọlọrun otitọ bura ; nitori ti a gbagbe wa-
hala iṣaju, ati nitoriti a fi wọn pamọ kuro
loju mi.
17 Sa wò o, emi o da ọrun titun ati aiye
titun : a kì yio si ranti awọn ti iṣaju, bẹ̃ni
nwọn kì yio wá si aiya.
18 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o yọ̀, ki inu nyin
ki o si dùn titi lai ninu eyi ti emi o da :
nitori kiyesi i, emi o da Jerusalemu ni inu-
didùn, ati awọn enia rẹ̀ ni ayọ̀.
19 Emi o si ṣe ariya ni Jerusalemu, emi
o si yọ̀ ninu awọn enia mi : a kì yio si
tun gbọ́ ohùn ẹkún mọ ninu rẹ̀, tabi ohùn
igbe.
20 Ki yio si ọmọ-ọwọ nibẹ ti ọjọ rẹ̀ kì
yio pẹ, tabi àgba kan ti ọjọ rẹ̀ kò kún : ni-
tori ọmọde yio kú li ọgọrun ọdun ; ṣugbọn
ẹlẹṣẹ ọlọgọrun ọdun yio di ẹni-ifibu.
21 Nwọn o si kọ ile, nwọn o si gbe inu
wọn ; nwọn o si gbìn ọgba àjara, nwọn o si
jẹ eso wọn.
22 Nwọn kì yio kọ ile fun ẹlomiran igbe,
nwọn kì yio gbìn fun ẹlomiran ijẹ : nitori
gẹgẹ bi ọjọ igi li ọjọ awọn enia mi ri, awọn
iyanfẹ mi yio si jìfà iṣẹ ọwọ́ wọn.
23 Nwọn kì yio ṣiṣẹ lasan, nwọn kì yio
bimọ fun wahala : nitori awọn ni iru ala-
bukun Oluwa ati iru-ọmọ wọn pẹlu wọn.
24 Yio si ṣe, pe, ki nwọn ki o to pè, emi
o dahùn ; ati bi nwọn ba ti nsọ̀rọ lọwọ,
emi o gbọ́.
25 Ikõko ati ọdọ-agutan yio jumọ jẹ pọ̀,
kiniun yio si jẹ koriko bi akọ-malu : erupẹ
ni yio jẹ onjẹ ejò. Nwọn kì yio panilara,
tabi ki nwọn panirun ni gbogbo oke mimọ́
mi, li Oluwa wi.

## ORI 66.

BAYI ni Oluwa wi, pe, Ọrun ni itẹ́ mi,
aiye si ni apoti itisẹ̀ mi : nibo ni ile
ti ẹ kọ́ fun mi gbe wà ? ati nibo ni isimi
mi gbe wà ?
2 Nitori gbogbo nkan wọnni li ọwọ́ mi
sa ti ṣe, gbogbo nkan wọnni si ti wà, li
Oluwa wi : ṣugbọn eleyi li emi o wò ani
òtoṣi ati oniròbinujẹ ọkàn, ti o si nwariri
si ọ̀rọ mi.
3 Ẹniti o pa akọ-malu, o dabi ẹnipe o pa
enia : ẹniti o fi ọdọ-agutan rubọ, a dabi
ẹnipe o bẹ́ ajá lọrùn ; ẹniti o rubọ ọrẹ, bi

Digitized by Google

ẹnipe o fi ẹ̀jẹ ẹlẹdẹ̀ rubọ; ẹniti o fi turari
jona, bi ẹniti o sure fun òrișa. Nitotọ,
nwọn ti yàn ọ̀na ara wọn, inu wọn si dùn
si ohun irira wọn.
4 Emi pẹlu yio yàn itanjẹ wọn, emi o si
mu eyi ti nwọn bẹ̀ru wá sara wọn, nitori
nigbati mo pè, kò si ẹnikan ti o dahùn;
nigbati mo sọ̀rọ, nwọn kò gbọ́: șugbọn
nwọn șe buburu niwaju mi, nwọn si yàn
eyiti inu mi kò dùn si.
5 Ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, ẹnyin ti o nwarìri
si ọ̀rọ rẹ̀; Awọn arakọnrin nyin ti nwọn
korira nyin, ti nwọn ta nyin nù nitori oru-
kọ mi, wipe, Jẹ ki a fi ogo fun Oluwa:
șugbọn on o fi ara hàn fun ayọ̀ nyin, oju
yio si tì awọn na.
6 Ohùn ariwo lati inu ilu wá, ohùn lati
inu tempeli wá, ohùn Oluwa ti nsan ẹ̀san
fun awọn ọta rẹ̀.
7 Ki o to rọbi, o bimọ; ki irora rẹ̀ ki o
to de, o bi ọmọkọnrin kan.
8 Tali o ti igbọ́ iru eyi ri? tali o ti iri
irú eyi ri? Ilẹ le hù nkan jade li ọjọ kan
bi? tabi a ha le bi orilẹ-ède li ẹrinkan?
nitori bi Sioni ti nrọbi gẹ, bẹ̃li o bi awọn
ọmọ rẹ̀.
9 Emi o ha mu wá si irọbi, ki mmá si
mu ki o bi? li Oluwa wi: emi o ha mu ni
bi, ki nsi se inu? li Ọlọrun rẹ wi.
10 Ẹ ba Jerusalemu yọ̀, ki inu nyin si
dùn pẹlu rẹ̀, gbogbo ẹnyin ti o fẹ ẹ; ẹ ba
a yọ̀ fun ayọ̀, gbogbo ẹnyin ti ngbãwẹ̀
fun u.
11 Ki ẹnyin ki o le mu ọmú, ki a si fi
ọmú itunu rẹ̀ tẹ́ nyin lọrùn; ki ẹnyin ki o
ba le fun wàra, ki inu nyin ba sì le dùn si
ọ̀pọlọpọ ogo rẹ.
12 Nitori bayi li Oluwa wi, Kiyesi i,
emi o nà alafia si i bi odò, ati ogo awọn
Keferi bi odò șișàn: nigbana li ẹnyin o mu
ọmú, a o dà nyin si ẹgbẹ́ rẹ̀, a o si ma gbe
nyin jo lori ẽkún rẹ̀.
13 Gẹgẹ bi ẹniti iya rẹ̀ ntù ninu, bẹ̃ni
emi o tù nyin ninu; a o si tù nyin ninu
ni Jerusalemu.
14 Nigbati ẹnyin ba ri eyi, ọkàn nyin
yio yọ̀, egungun nyin yio si tutu yọ̀yọ bi
ewebẹ̀; a o si mọ̀ ọwọ́ Oluwa lara awọn
iranșẹ rẹ̀, ati ibinu rẹ̀ si awọn ọta rẹ̀.
15 Nitori kiyesi i, Oluwa mbọ wá ti on
ti iná, ati awọn kẹkẹ́ rẹ̀ bi ãjà, lati fi irunu
sẹsan ibinu rẹ̀, ati ibawi rẹ̀ nipa ọwọ́ iná.
16 Nitori Oluwa yio fi iná ati idà rẹ̀ șe
idajọ gbogbo ẹran-ara; awọn okú Oluwa
yio si pọ̀.
17 Awọn ti o yà ara wọn si mimọ́, ti
nwọn si sọ ara wọn di mimọ́ ninu agbala
wọnni, ti ọkan tẹle ekeji li ãrin, nwọn njẹ
ẹran ẹlẹdẹ, ati ohun irira, ati eku, awọn li
a o parun pọ̀; li Oluwa wi.
18 Nitori emi mọ̀ iṣẹ ati ìro wọn: igba
na yio dé lati ṣà gbogbo awọn orilẹ-ède
ati ahọn jọ, nwọn o si wá, nwọn o si ri ogo
mi.
19 Emi o si fi àmi kan si ãrin wọn, emi
o si rán awọn ti o salà ninu wọn si awọn
orilẹ-ède, si Tarșiși, Puli, ati Ludi, awọn
ti nfà ọrun, si Tubali, on Jafani, si awọn
erekușu ti o jina rére, ti nwọn kò ti igbọ́
okiki mi, ti nwọn kò si ti iri ogo mi; nwọn
o si rohin ogo mi lãrin awọn Keferi.
20 Nwọn o si mu gbogbo awọn arakọnrin
nyin lati orilẹ-ède gbogbo wá, ẹbọ kan si
Oluwa lori ẹṣin, ati ninu kẹkẹ́, ati ninu
páfa, ati lori ibaka, ati lori rakunmi, si
Jerusalemu oke-nla mimọ́ mi; li Oluwa
wi, gẹgẹ bi awọn ọmọ Israeli ti imu ọrẹ wá
ninu ohunelò mimọ́ sinu ile Oluwa.
21 Ninu wọn pẹlu li emi o si mu șe alufa
ati Lefite; li Oluwa wi.
22 Nitori gẹgẹ bi awọn ọrun titun, ati
aiye titun, ti emi o șe, yio ma duro niwaju
mi, bẹ̃ni iru-ọmọ rẹ ati orukọ rẹ yio duro,
li Oluwa wi.
23 Yio si șe, gbogbo ẹran-ara yio si wá
tẹriba niwaju mi, lati oșù titun de oșù
titun, ati lati ọjọ isimi de ọjọ isimi, li
Oluwa wi.
24 Nwọn o si jade lọ, nwọn o si wò okú
awọn ti o ti ṣọtẹ si mi: nitori kokoro wọn
kì yio kú, bẹ̃ni iná wọn kì yio si kú; nwọn
o si jẹ ohun irira si gbogbo eran-ara.

Digitized by Google

IWE WOLI

# JEREMIAH.

## ORI 1.

ỌRỌ Jeremiah, ọmọ Hilkiah, ọkan ninu
awọn alufa ti o wà ni Anatoti, ni ilẹ
Benjamini.
2 Ẹniti ọ̀rọ Oluwa tọ̀ wá ni igba ọjọ
Josiah, ọmọ Amoni, ọba Juda, li ọdun
kẹtala ijọba rẹ̀.
3 O si tọ̀ ọ wá pẹlu ni igba ọjọ Jehoia-
kimu, ọmọ Josiah, ọba Juda, titi de opin
ọdun kọkanla Sedekiah, ọmọ Josiah, ọba
Juda, ani de igba ti o kó Jerusalemu lọ ni
igbekun li oṣu karun.
4 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá wipe:
5 Ki emi ki o to dá ọ ni inu, emi ti mọ̀
ọ, ki iwọ ki o si to ti inu jade wá li emi ti
sọ ọ di mimọ́, emi si yà ọ sọtọ ṣe woli fun
awọn orilẹ-ède.
6 Emi si wipe, Oluwa Ọlọrun! sa wò o,
emi kò mọ̀ ọ̀rọ isọ nitori ọmọde li emi.
7 Ṣugbọn Oluwa wi fun mi pe, má wipe,
ọmọde li emi: ṣugbọn iwọ o lọ sọdọ ẹni-
kẹni ti emi o ran ọ si, ati ohunkohun ti
emi o paṣẹ fun ọ ni iwọ o sọ.
8 Má bẹ̀ru niwaju wọn nitori emi wà
pẹlu rẹ lati gbà ọ: li Oluwa wi.
9 Oluwa si nà ọwọ rẹ̀, o fi bà ẹnu mi;
Oluwa si wi fun mi pe, sa wò o, emi fi ọ̀rọ
mi si ọ li ẹnu.
10 Wò o, li oni yi ni mo fi ọ ṣe olori
awọn orilẹ-ède, ati olori ijọba wọnni, lati
fàtu, ati lati fà lulẹ; lati parun, ati lati
wó lulẹ; lati kọ́, ati lati gbin.
11 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá wipe, Jere-
miah, kini iwọ ri? emi si wipe, mo ri ọpa
igi almondi.
12 Oluwa si wi fun mi pe, iwọ riran
rere, nitori ti emi o kiye si ọ̀rọ mi lati mu
u ṣẹ.
13 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá lẹ̃keji pe, kini
iwọ ri? emi si wipe, mo ri ìkoko ori iná,
oju rẹ̀ si ni lati iha ariwa wá.
14 Nigbana ni Oluwa sọ fun mi pe, ibi
yio tú jade lati ariwa wá, sori gbogbo awọn
ti ngbe inu ilẹ.
15 Sa wò o, Emi o pè gbogbo idile awọn
ijọba ariwa, li Oluwa wi, nwọn o si wá:
olukuluku wọn o si tẹ́ itẹ rẹ̀ li ẹnu-bode
Jerusalemu, ati lori gbogbo odi rẹ̀ yikakiri,
ati lori gbogbo ilu Juda.
16 Emi o si sọ̀rọ idajọ mi si wọn nitori
gbogbo buburu wọn; ti nwọn ti kọ̀ mi silẹ,
ti nwọn ti sun turari fun ọlọrun miran, ti
nwọn si tẹriba fun iṣẹ ọwọ wọn.
17 Ṣugbọn iwọ di ẹgbẹ́ rẹ li amure, ki o
si dide, ki o si wi fun wọn gbogbo ohun ti
emi o pa laṣẹ fun ọ, má fòya niwaju wọn,
ki emi ki o má ba mu ọ dãmu niwaju wọn.
18 Sa wò o, loni ni mo fi ọ ṣe ilu-odi, ati
ọwọ̀n irin, ati odi idẹ fun gbogbo ilẹ; fun
awọn ọba Juda, awọn ijoye rẹ̀, awọn alufa,
ati enia ilẹ na.
19 Ṣugbọn nwọn o ba ọ jà, nwọn ki o si
le bori rẹ; nitori emi wà pẹlu rẹ, li Oluwa
wi, lati gbà ọ.

## ORI 2.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá wipe,
2 Lọ, ki o si ke li eti Jerusalemu
wipe, Bayi li Oluwa wi, Emi ranti rẹ, iṣeun
igbà ọmọde rẹ, ifẹ igbeyawo rẹ, nigbati
iwọ tẹle mi ni iju, ni ilẹ ti a kì igbin si.
3 Mimọ́ ni Israeli fun Oluwa, akọso eso
oko rẹ̀, ẹnikẹni ti o fi jẹ yio jẹbi; ibi yio si
wá si ori wọn, li Oluwa wi.
4 Ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, ẹnyin ara-ile Jako-
bu, ati gbogbo iran ile Israeli:
5 Bayi li Oluwa wi: Aiṣedede wo li
awọn baba nyin ri lọwọ mi ti nwọn lọ jina
kuro lọdọ mi, ti nwọn si tẹle asan, ti nwọn
si di enia asan?
6 Bẽni nwọn kò si wipe, nibo li Oluwa
wà? ti o mu wa goke lati ilẹ Egipti wá, ti
o mu wa rìn ninu iju, ninu ilẹ pẹtẹlẹ ati
ihò, ninu ilẹ gbigbẹ ati ojiji ikú, ninu ilẹ
ti enia kò là kọja, ati nibiti enia kò tẹdo
si.
7 Emi si mu nyin wá si ilẹ ọgba-eso,
lati jẹ eso rẹ̀ ati ire rẹ̀; ṣugbọn enyin wọ
inu rẹ̀, ẹ si ba ilẹ mi jẹ, ẹ si sọ ogún mi di
ohun irira:



Digitized by Google

8 Awọn alufa kò wipe, Nibo li Oluwa
wà? ati awọn ti o mu ofin lọwọ kò mọ mi:
awọn oluṣọ si ṣẹ̀ si mi, ati awọn woli sọ
asọtẹlẹ nipa Baali, nwọn si tẹle ohun ti kò
lerè.
9 Nitorina, Emi o ba nyin jà, li Oluwa
wi, Emi o si ba atọmọde-ọmọ nyin jà.
10 Njẹ, ẹ kọja lọ si erekuṣu awọn ara
Kittimu, ki ẹ si wò, si ranṣẹ lọ si Kedari,
ki ẹ si ṣe akiyesi gidigidi, ki ẹ wò bi iru
nkan yi ba mbẹ nibẹ?
11 Orilẹ-ède kan ha pa ọlọrun rẹ̀ dà?
sibẹ awọn wọnyi kì iṣe ọlọrun! ṣugbọn
enia mi ti yi ogo wọn pada fun eyiti kò
lerè.
12 Ki ẹnu ki o ya ọrun nitori eyi, ki o
si dãmu, ki o si di gbigbẹ, li Oluwa wi!
13 Nitori awọn enia mi ṣe ibi meji:
nwọn fi Emi, isun omi-ìye silẹ, nwọn si wà
kanga omi fun ara wọn, kanga fifọ̀ ti kò le
da omi duro.
14 Ẹrú ni Israeli iṣe bi? tabi ẹru ibile?
ẽṣe ti o fi di ijẹ.
15 Awọn ọmọ kiniun ke ramuramu lori
rẹ̀, nwọn si bú, nwọn si sọ ilẹ rẹ̀ di ahoro,
ilu rẹ̀ li a fi jona li aini olugbe.
16 Awọn ọmọ Nofi ati ti Tafanesi pẹlu
ti jẹ agbari rẹ;
17 Fifi Oluwa Ọlọrun rẹ silẹ kọ̀ ha mu
eyi ba ọ, nigbati o tọ́ ọ loju ọ̀na?
18 Njẹ nisisiyi kini iwọ ni iṣe ni ipa-ọ̀na
Egipti, lati mu omi Sihori? tabi kini iwọ
ni iṣe ni ipa-ọ̀na Assiria lati mu omi odò
rẹ̀.
19 Ìwa-buburu rẹ ni yio kọ́ ọ, ipadasẹ-
hin rẹ ni yio si ba ọ wi: mọ̀, ki iwọ si ri i
pe, ohun buburu ati kikoro ni, pe, iwọ ti
kọ̀ Oluwa Ọlọrun rẹ, ati pe ìbẹru mi kò si
si niwaju rẹ; li Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-
ogun wi.
20 Nitori ni igba atijọ iwọ ti ṣẹ́ ajaga
ọrun rẹ, iwọ si já idè rẹ; iwọ si wipe, Emi
kì o sìn, nitori lori oke giga gbogbo, ati
labẹ igi tutu gbogbo ni iwọ nṣe panṣaga.
21 Ṣugbọn emi ti gbin ọ ni ajara ọlọla,
irugbin rere patapata: ẽṣe ti iwọ fi yipada
di ẹka ajara ajeji si mi?
22 Nitori iwọ iba wẹ ara rẹ ni ẽru, ki o
si mu aró-ẹ̀ba pupọ, ẽri ni ẹ̀ṣẹ̀ rẹ niwaju mi
sibẹsibẹ, li Oluwa Ọlọrun wi.
23 Bawo li o ṣe wipe, emi kò ṣe alaimọ́,
emi kò tẹpa Baalimu? wò ọ̀na rẹ li afoni-
foji, mọ̀ ohun ti iwọ ti ṣe, iwọ dabi abo
ibakasiẹ ayasẹ̀ ti nrin ọ̀na rẹ̀ ka.
24 Kẹtẹkẹtẹ igbẹ ti ima gbe aginju, ni-
nu ifẹ ọkàn rẹ̀ ti nfa ẹfufu, li akoko rẹ̀,
tani le yi i pada? gbogbo awọn ti nwá a
kiri kì yio da ara wọn li agara, nwọn o ri i
li oṣu rẹ̀.
25 Da ẹsẹ̀ rẹ duro nini aiwọ bàta, ati
ọfun rẹ ninu ongbẹ: ṣugbọn iwọ wipe,
lasan ni! bẹ̃kọ, nitoriti emi ti fẹ awọn ale-
jo, awọn li emi o tọ̀ lẹhin.
26 Gẹgẹ bi oju ti itì ole nigbati a ba mu
u, bẹ̃li oju tì ile Israeli: awọn ọba wọn,
ijoye wọn, alufa wọn, ati woli wọn pẹlu.
27 Ti nwọn wi fun igi pe, Iwọ ni baba
mi; ati fun okuta pe, iwọ li o bi mi.
Nitori nwọn ti yi ẹ̀hìn wọn pada si mi kì
iṣe iwaju wọn: ṣugbọn ni igba ipọnju wọn,
nwọn o wipe, Dide, ki o gbani.
28 Njẹ nibo li awọn ọlọrun rẹ wà, ti iwọ
ti da fun ara rẹ? jẹ ki nwọn ki o dide, bi
nwọn ba le gba ọ nigba ipọnju rẹ, nitori bi
iye ilu rẹ, bẹ̃li ọlọrun rẹ, iwọ Juda.
29 Ẽṣe ti ẹnyin o ba mi jà? gbogbo nyin
li o ti rufin mi, li Oluwa wi.
30 Lasan ni mo lù ọmọ nyin, nwọn kò
gbà ibawi, idà ẹnyin tikara nyin li o pa
awọn woli bi kiniun apanirun.
31 Iran enia yi, ẹ kiyesi ọ̀rọ Oluwa.
Emi ha ti di aginju si Israeli bi? tabi ilẹ
okunkun biribiri, ẽṣe ti enia mi wipe, awa
nrin kakiri, awa kì yio tọ̀ ọ wá mọ.
32 Wundia le gbagbe ohun ọṣọ rẹ̀, tabi
iyawo ọjá-ọṣọ rẹ̀? ṣugbọn enia mi ti gbagbe
mi li ọjọ ti kò ni iye.
33 Ẽṣe ti iwọ tun ọ̀na rẹ ṣe lati wá ifẹ
rẹ? nitorina iwọ ṣe kọ́ awọn obirin buburu
li ọ̀na rẹ.
34 Pẹlupẹlu ẹjẹ ẹmi awọn talaka ati
alaiṣẹ mbẹ lara aṣọ rẹ, iwọ kò ri wọn nibi
irunlẹ wọle, ṣugbọn lara gbogbo wọnyi.
35 Sibẹ iwọ wipe, alaiṣẹ̀ li emi, ibinu rẹ̀
yio sa yipada lọdọ mi. Sa wò o, emi o ba
ọ jà, nitori iwọ wipe, emi kò ṣẹ̀.
36 Ẽṣe ti iwọ ṣe ati yi ọ̀na rẹ pada bẹ̃,
oju yio tì ọ pẹlu fun Egipti, gẹgẹ bi oju ti
tì ọ fun Assiria.
37 Lõtọ iwọ o kuro lọdọ rẹ̀, iwọ o si ka
ọwọ le ori, nitori Oluwa ti kọ̀ awọn oni-
gbẹkẹle rẹ, iwọ kì yio si ṣe rere ninu wọn.

## ORI 3.

SA wò o, bi a wipe ọkọnrin kan kọ̀ aya rẹ̀
silẹ, ti aya na si kuro lodọ rẹ̀, ti o si
di aya ẹlomiran, ọkọnrin na le tun tọ̀ ọ
wá? ilẹ na kì yio di ibajẹ gidigidi? ṣugbọn
iwọ ti ba ayanfẹ pupọ ṣe panṣaga, iwọ o
tun tọ̀ mi wá! li Oluwa wi.
2 Gbe oju rẹ soke si ibi giga wọnnì, ki o
si wò, nibo ni a kò ti bà ọ jẹ? Iwọ joko

Digitized by Google

de wọn li oju ọ̀na, bi ara Arabia kan ni iju,
iwọ si ti fi agbere ati ìwa buburu rẹ bà ilẹ
na jẹ.
3 Nitorina emi fa ọ̀wara ọ̀jo sẹhin, kò si
ọ̀jo arọkuro, sibẹ iwọ ni iwaju agbere, iwọ
kọ̀ lati tiju.
4 Lõtọ lati isisiyi, iwọ kì yio ha pè mi
pe, Baba mi ! iwọ li ayanfẹ ìgba-ewe mi ?
5 On o ha pa ibinu rẹ̀ mọ lailai ? yio pa
a mọ de opin ? sa wò o, bayi ni iwọ ti wi,
ṣugbọn iwọ ṣe ohun buburu li aidẹkun.
6 Oluwa si wi fun mi ni igba Josiah
ọba, pe, Iwọ ri ohun ti Israeli apẹhinda ti
ṣe ? o ti gun ori oke giga gbogbo, ati labẹ
gbogbo igi tutu, nibẹ li o ti ṣe panṣaga.
7 Emi si wipe, lẹhin ti o ti ṣe gbogbo
ohun wọnyi tan, yio yipada si mi, ṣugbọn
kò yipada, Juda alarekereke arabirin rẹ̀ si
ri i.
8 Emi si wò pe, nitori gbogbo wọnyi ti
Israeli apẹhinda ti ṣe agbere, ti mo kọ̀ ọ
silẹ, ti emi si fun u ni iwe-ikọsilẹ, sibẹ
Juda, alarekereke arabirin rẹ̀, kò bẹru, o si
nṣe agbere lọ pẹlu.
9 O si ṣe nitori okìki àgbere rẹ̀ li o fi bà
ilẹ jẹ, ti o si ṣe àgbere tọ̀ okuta ati igi lọ.
10 Lẹhin gbogbo wọnyi, sibẹ Juda, ala-
rekereke arabirin rẹ̀, kò yipada si mi tọkàn-
tọkàn ṣugbọn li agabagebe ; li Oluwa wi.
11 Oluwa si wi fun mi pe, Israeli apẹ-
hinda, ti dá ara rẹ̀ li are ju Juda alareke-
reke lọ.
12 Lọ ki o si kede ọ̀rọ wọnyi ni iha ariwa,
ki o si wipe, Yipada iwọ Israeli, apẹhinda,
li Oluwa wi, emi kì yio jẹ ki oju mi ki o
korò si ọ ; nitori emi ni ãnu, li Oluwa wi,
emi kì o si pa ibinu mi mọ titi lai.
13 Sa jẹwọ ẹ̀ṣẹ rẹ pe, iwọ ti ṣẹ̀ si Oluwa
Ọlọrun rẹ, ati pe, o si tú ọ̀na rẹ ka fun
awọn alejo labẹ igi tutu gbogbo, ṣugbọn
ẹnyin kò gba ohùn mi gbọ́, li Oluwa wi.
14 Pada, ẹnyin apẹhinda ọmọ, li Oluwa
wi, nitori emi gbe nyin ni iyawo ; emi o si
mu nyin, ọkan ninu ilu kan, ati meji ninu
idile kan ; emi o si mu nyin wá si Sioni.
15 Emi o si fun nyin li oluṣọ-agutan
gẹgẹ bi ti inu mi, ti yio fi ìmọ ati oye bọ́
nyin.
16 Yio si ṣe nigbati ẹnyin ba pọ̀ si i, ti ẹ
si dàgba ni ilẹ na, li ọjọ wọnni, li Oluwa
wi ; nwọn kì yio si tun le wipe, Apoti-ẹri
majẹmu Oluwa ; bẽni kì yio wọ inu wọn,
nwọn kì yio si ranti rẹ̀, nwọn kì yio tọ̀ ọ
wá pẹlu, bẽni a kì yio si tun ṣe e mọ.
17 Nigbana ni nwọn o pè Jerusalemu ni
itẹ Oluwa ; gbogbo orilẹ-ède yio kọja tọ̀ ọ
wá si orukọ Oluwa, si Jerusalemu, bẽni
nwọn kì yio rin mọ nipa agidi ọkàn buburu
wọn,
18 Li ọjọ wọnnì, ile Juda yio rin pẹlu ile
Israeli, nwọn o jumọ wá lati ilẹ ariwa, si
ilẹ ti emi ti fi fun awọn baba nyin li ogún.
19 Emi si wipe, Bawo li emi o ṣe gbe ọ
kalẹ pẹlu awọn ọmọ, ati lati fun ọ ni ilẹ
ayanfẹ, ogún daradara, ani ogún awọn
orilẹ-ède ? Emi si wipe, Iwọ o pè mi ni,
Baba mi ! iwọ kì o si pada kuro lọdọ mi.
20 Nitõtọ gẹgẹ bi aya ti ifi arekereke lọ
kuro lọdọ ọkọ rẹ̀, bẽni ẹnyin ti hùwa are-
kereke si mi, iwọ ile Israeli : li Oluwa wi.
21 A gbọ́ ohùn kan lori ibi giga, ẹkun,
ani ẹ̀bẹ awọn ọmọ Israeli pe : nwọn ti bà
ọ̀na wọn jẹ, nwọn si ti gbagbe Oluwa,
Ọlọrun wọn.
22 Yipada, ẹnyin ọmọ apẹhinda, emi o
si wò ipẹhinda nyin sàn ; Sa wò o, awa tọ̀
ọ wá, nitori iwọ li Oluwa Ọlọrun wa !
23 Lotitọ asan ni eyi ti o ti oke wá, ani
ọ̀pọlọpọ oke giga, lõtọ ninu Oluwa Ọlọrun
wa ni igbala Israeli wà.
24 Ṣugbọn ohun itiju oriṣa ti jẹ ère iṣẹ
awọn baba wa lati igba ewe wa wá, ọwọ́-
ẹran wọn ati agbo-ẹran wọn, pẹlu ọmọ-
kọnrin ati ọmọbirin wọn.
25 Awa dubulẹ ninu itiju wa, rudurudu
wa bò wa mọlẹ, nitoriti awa ti ṣẹ̀ si Oluwa
Ọlọrun wa, awa pẹlu awọn baba wa, lati
igba ewe wa wá, titi di oni yi, awa kò gba
ohùn Oluwa Ọlọrun wa gbọ́.

## ORI 4.

ISRAELI bi iwọ o ba yipada, li Oluwa wi,
yipada sọdọ mi ; ati bi iwọ o ba mu
irira rẹ kuro niwaju mi, iwọ kì o si rìn
kiri :
2 Iwọ o si bura pe, Oluwa mbẹ ni otitọ,
ni idajọ, ati ni ododo ; ati nipasẹ rẹ̀ ni
gbogbo orilẹ-ède yio fi ibukun fun ara wọn,
nwọn o si ṣe ogo ninu rẹ̀.
3 Nitori bayi li Oluwa wi fun awọn
ọkọnrin Juda, ati Jerusalemu pe, Tú ilẹ
titun fun ara nyin, ki ẹ má si gbìn lãrin
ẹ̀gun.
4 Ẹ kọ ara nyin ni ilà fun Oluwa, ki ẹ
si mu awọ ikọla ọkàn nyin kuro, ẹnyin
enia Juda ati olugbe Jerusalemu, ki ikannu
mi ki o má ba jade bi iná, ki o si jo tọbẽ ti
kò si ẹniti o le pa a, nitori buburu iṣe nyin.
5 Ẹ kede ni Juda, ki ẹ si pokikí ni
Jerusalemu ; ki ẹ si wipe, ẹ fun fère ni ilẹ
na, ẹ ké, ẹ kojọ pọ̀, ki ẹ si wipe ; Pè apejọ
ara nyin, ki ẹ si lọ si ilu olodi wọnnì.

Digitized by Google

6 Ẹ gbé ọpagun soke siha Sioni; ẹ kuro, ẹ má duro: nitori emi o mu buburu lati ariwa wá pẹlu ibajẹ nlanla.

7 Kiniun jade wá lati inu pantiri rẹ̀, ati olubajẹ awọn orilẹ-ède dide: o jade kuro ninu ipo rẹ̀ lati sọ ilẹ rẹ di ahoro; ati ilu rẹ di ofo, laini olugbe.

8 Nitori eyi, di amure aṣọ ọ̀fọ, pohùnrere ki o si sọkun: nitori ibinu gbigbona Oluwa kò lọ kuro lọdọ wa.

9 Yio si ṣe li ọjọ na, li Oluwa wi, ọkàn ọba yio nù, ati ọkàn awọn ijoye: awọn alufa yio si dãmu, hà yio si ṣe awọn woli.

10 Nigbana ni mo wipe, Ye! Oluwa Ọlọrun! nitõtọ iwọ ti tan awọn enia yi ati Jerusalemu jẹ gidigidi, wipe, Ẹnyin o ni alafia; nigbati idà wọ inu ọkàn lọ.

11 Nigbana ni a o wi fun awọn enia yi ati fun Jerusalemu pe, Ẹfũfu gbigbona lati ibi giga ni iju niha ọmọbirin enia mi, ki iṣe lati fẹ, tabi lati fẹnù.

12 Ẹfũfu ti o lagbara jù wonyi lọ yio fẹ fun mi: nisisiyi emi pẹlu yio sọrọ idajọ si wọn.

13 Sa wò o, on o dide bi awọsanma, kẹkẹ rẹ̀ yio dabi ìji: ẹṣin rẹ̀ yara jù idì lọ. Egbe ni fun wa! nitori awa di ijẹ.

14 Jerusalemu! wẹ ọkàn rẹ kuro ninu buburu, ki a ba le gba ọ là. Yio ti pẹ to ti iro asan yio wọ̀ si inu rẹ.

15 Nitori ohùn kan kede lati Dani wá, o si pokiki ipọnju lati oke Efraimu.

16 Ẹ wi fun awọn orilẹ-ède; sa wò o, kede si Jerusalemu, pe, awọn ọluṣọ-ogun ti ilẹ jijin wá, nwọn si sọ ohùn wọn jade si ilu Juda.

17 Bi awọn ti nṣọ oko, bẹ̃ni nwọn wà yi i kakiri: nitori o ti ṣọtẹ̀ si mi, li Oluwa wi.

18 Ìwa rẹ ati iṣe rẹ li o ti mu gbogbo ohun wọnyi bá ọ; eyi ni buburu rẹ, nitoriti o korò, nitoriti o de ọkàn rẹ.

19 Inu mi, inu mi! ẹ̀dun dùn mi jalẹ de ọkàn mi; ọkàn mi npariwo ninu mi; emi kò le dakẹ, Nitoriti iwọ, ọkàn mi, ngbọ́ iro fère, ati idagiri ogun.

20 Iparun lori iparun ni a nke; nitori gbogbo ilẹ li o ti parun, lojiji ni agọ mi di ijẹ, pẹlu aṣọ ikele mi ni iṣẹju kan.

21 Yio ti pẹ to ti emi o ri ọpagun, ti emi o si gbọ́ iro fère?

22 Nitori òpe li enia mi, nwọn kò mọ̀ mi; alaimoye ọmọ ni nwọn iṣe, nwọn kò si ni ìmọ: nwọn ni ọgbọ́n lati ṣe ibi, ṣugbọn oye ati ṣe rere ni nwọn kò ni.

23 Mo bojuwo aiye, sa wò o, o wà ni jũju, o si ṣofo; ati ọrun, imọlẹ kò si lara rẹ̀.

24 Mo bojuwo gbogbo oke nla, sa wò o, o wariri, ati gbogbo oke kekere mì jẹjẹ.

25 Mo bojuwo, sa wò o, kò si enia kan, pẹlupẹlu gbogbo ẹiyẹ oju-ọrun sa lọ.

26 Mo bojuwo, sa wò o, Karmeli di aginju, ati gbogbo ilu rẹ̀ li o wó lulẹ, niwaju Oluwa ati niwaju ibinu rẹ̀ gbigbona.

27 Nitori bayi li Oluwa wi pe: Gbogbo ilẹ ni yio di ahoro; ṣugbọn emi ki yio ṣe ipari tan.

28 Nitori eyi ni ilẹ yio ṣe kãnu, ati ọrun loke yio di dudu: nitori emi ti wi i, mo ti pete rẹ̀, emi ki o yi ọkàn da, bẹ̃ni ki o yipada kuro ninu rẹ̀.

29 Gbogbo ilu ni yio sá nitori ariwo awọn ẹlẹṣin ati awọn tafatafa; nwọn o lọ sinu igbo; nwọn o si gun ori oke okuta lọ, gbogbo ilu ni a o kọ̀ silẹ, ẹnikan ki yio gbe inu wọn.

30 Ati iwọ, eniti o di ijẹ tan, kini iwọ o ṣe? Iwọ iba wọ ara rẹ ni aṣọ òdodó, iwọ iba fi wura ṣe ara rẹ lọṣọ, iwọ iba fi tirõ kun oju rẹ: lasan ni iwọ o ṣe ara rẹ daradara, awọn ayanfẹ rẹ yio kọ̀ ọ silẹ, nwọn o wá ẹmi rẹ.

31 Nitori mo ti gbọ́ ohùn kan bi ti obirin ti nrọbi, irora bi obirin ti nbi akọbi ọmọ rẹ̀, ohùn ọmọbirin Sioni ti npohùnrere ẹkun ara rẹ̀, ti o nnà ọwọ rẹ̀ wipe: Egbe ni fun mi nisisiyi nitori ãrẹ mu mi li ọkàn, nitori awon apania.

## ORI 5.

ERÌN kiri la ita Jerusalemu ja, ki ẹ si wò nisisiyi, ki ẹ si mọ̀, ki ẹ si wakiri nibi gbigbòro rẹ̀, bi ẹ ba lè ri ẹnikan, bi ẹnikan wà ti nṣe idajọ, ti o nwá otitọ; emi o si dari jĩ i.

2 Bi nwọn ba si wipe, Oluwa mbẹ; sibẹ nwọn bura eke.

3 Oluwa, oju rẹ kò ha wà lara otitọ? iwọ ti lù wọn, ṣugbọn kò dùn wọn; iwọ ti run wọn, ṣugbọn nwọn kọ̀ lati gba ẹkọ: nwọn ti mu oju wọn le jù apata lọ; nwọn kọ̀ lati yipada.

4 Emi si wipe, Lõtọ talaka enia ni awọn wọnyi, nwọn kò ni oye, nitori nwọn kò mọ̀ ọ̀na Oluwa, tabi idajọ Ọlọrun wọn.

5 Emi o tọ̀ awọn ẹni-nla lọ, emi o si ba wọn sọrọ: nitori nwọn ti mọ̀ ọ̀na Oluwa, idajọ Ọlọrun wọn. Ṣugbọn awọn wọnyi ti jumọ ṣẹ́ àjaga, nwọn si ti ja ìde.

6 Nitorina kiniun lati inu igbo wa yio pa wọn, ikõko aṣálẹ̀ yio pa wọn run, ẹkùn yio mã ṣọ ilu wọn: ẹnikẹni ti o ba ti ibẹ

Digitized by Google

jade li a o ya pẹrẹpẹrẹ: nitori ẹ̀ṣẹ wọn pọ̀,
ati ipẹhinda wọn le.
7 Emi o ha ṣe dari eyi ji ọ? awọn ọmọ
rẹ ti kọ̀ mi silẹ, nwon si fi eyi ti kì iṣe ọlọ-
run bura: emi ti mu wọn bura, ṣugbọn
nwọn ṣe panṣaga, nwọn si kó ara wọn jọ si
ile àgbere.
8 Nwọn jẹ akọ ẹṣin ti a bọ́ rere ti nrin
kiri, olukuluku nwọn nyán si aya aladu-
gbo rẹ̀.
9 Emi kì yio ha ṣe ibẹwo nitori nkan
wọnyi? li Oluwa wi, ọmi mi kì yio ha
gbẹsan lara iru orilẹ-ède bi eyi?
10 Ẹ goke lọ si ori odi rẹ̀, ki ẹ si parun;
ṣugbọn ẹ máṣe ipari tan: ẹ wó kùrùkúrù rẹ̀
kuro nitori nwọn kì iṣe ti Oluwa.
11 Nitori ile Israeli ati ile Juda ti huwa
arekereke gidigidi si mi, li Oluwa wi.
12 Nwọn sẹ Oluwa, wipe, Kì iṣe on, ibi
kò ni wá si ori wa, awa kì yio si ri idà tabi
ìyan:
13 Awọn woli yio di ẹfufu, ọ̀rọ kò sì si
ninu wọn; bayi li a o ṣe si wọn.
14 Nitorina bayi li Oluwa, Ọlọrun awọn
ọmọ-ogun wi, nitori ẹnyin sọ ọ̀rọ yi, sa
wò o, emi o sọ ọ̀rọ mi li ẹnu rẹ di iná,
ati awọn enia yi di igi, yio si jo wọn
run.
15 Wò o emi o mu orilẹ-ède kan wá sori
nyin lati ọ̀na jijin, ẹnyin ile Israeli, li
Oluwa wi, orile-ède alagbara ni, orilẹ-ède
lati igbãni wá ni, orilẹ-ède ti iwọ kò mọ̀
ede rẹ̀, bẽni iwọ kò gbọ́ eyiti o nwi.
16 Apó ọfa rẹ̀ dabi isa-okú ti a ṣi, akọni
enia ni gbogbo wọn.
17 On o si jẹ ikore rẹ ati onjẹ rẹ, nwọn
o jẹ awọn ọmọkọnrin ati awọn ọmọbirin rẹ,
nwọn o si jẹ agbo rẹ ati ọwọ́-ẹran rẹ, nwọn
o jẹ àjara rẹ ati igi ọ̀pọtọ rẹ, nwọn o fi idà
sọ ilu olodi rẹ ti iwọ gbẹkẹle di ahoro.
18 Ṣugbọn li ọjọ wọnni, li Oluwa wi,
emi kì yio ṣe iparun nyin patapata.
19 Yio si ṣẹ, nigbati ẹnyin o wipe: Ẽṣe
ti Oluwa Ọlọrun wa fi ṣe gbogbo ohun
wọnyi si wa? nigbana ni iwọ o da wọn
lohùn: Gẹgẹ bi ẹnyin ti kọ̀ mi, ti ẹnyin si
nsìn ọlọrun ajeji ni ilẹ nyin, bẽni ẹnyin o
sin alejo ni ilẹ ti kì iṣe ti nyin.
20 Kede eyi ni ile Jakobu, pokiki rẹ̀ ni
Juda wipe,
21 Ẹ gbọ́ eyi nisisiyi, ẹnyin aṣiwere enia
ati alailọgbọ́n; ti o ni oju, ti kò si riran,
ti o ni eti ti kò si gbọ́.
22 Ẹ kò ha bẹ̀ru mi; li Oluwa wi, ẹ kì
yio warìri niwaju mi, ẹniti o fi yanrin ṣe
ipãla okun, ofin lailai ti kò le rekọja:
ìgbì rẹ̀ kọlu u, kò si le bori rẹ̀, o pariwo,
ṣugbọn kò lè re e kọja?
23 Ṣugbọn enia yi ni aiya iṣàgun ati
iṣọtẹ si, nwọn sọ̀tẹ, nwọn si lọ.
24 Bẽni nwọn kò wi li ọkàn wọn pe, Ẹ
jẹ ki a bẹ̀ru Oluwa Ọlọrun wa wayi, ẹniti
o fun wa ni òjo akọrọ ati arọkuro ni igba
rẹ̀: ti o fi ọ̀sẹ ikore ti a pinnu pamọ fun wa.
25 Aiṣedede nyin ti yi gbogbo ohun
wọnyi pada, ati ẹ̀ṣẹ nyin ti fà ohunrere
sẹhin kuro lọdọ nyin.
26 Nitori lãrin enia mi ni a ri enia ìka,
nwọn wò kakiri, bi biba ẹniti ndẹ ẹiyẹ,
nwọn dẹ okùn nwọn mu enia.
27 Bi àgo ti o kún fun ẹiyẹ bẽni ile wọn
kún fun ẹ̀tan, nitorina ni nwọn ṣe di nla,
nwọn si di ọlọrọ̀.
28 Nwọn sanra, nwọn ndán, pẹlupẹlu
nwọn rekọja ni ìwa-buburu, nwọn kò ṣe
idajọ, nwọn kò dajọ ọ̀ran alainibaba, ki
nwọn le ri rere; nwọn kò si dajọ are awọn
talaka.
29 Emi kì yio ha ṣe ibẹwò nitori nkan
wọnyi, li Oluwa wi, ọmi mi kì yio ha gbẹ-
san lori orilẹ-ède bi eyi?
30 Ohun iyanu ati irira li a ṣe ni ilẹ na.
31 Awọn woli sọ asọtẹlẹ eke, ati awọn
alufa ṣe akoso labẹ ọwọ wọn, awọn enia mi
si fẹ ki o ri bẽ; kini ẹnyin o si ṣe ni igbẹ-
hin rẹ̀?

## ORI 6.

ẸNYIN ọmọ Benjamini, ẹ ko ẹrù nyin
salọ kuro li arin Jerusalemu, ẹ si fun
fère ni Tekoa, ki ẹ si gbe àmi soke ni Bet-
hakeremu, nitori ibi farahàn lati ariwa wá;
ani iparun nlanla.
2 Emi ti pa ọmọbirin Sioni run, ti o ṣe
ẹlẹgẹ ati ẹlẹwà.
3 Awọn oluṣọ-agutan pẹlu agbo wọn yio
tọ̀ ọ wá, nwọn o pa agọ wọn yi i ka, oluku-
luku yio ma jẹ ni àgbegbe rẹ̀.
4 Ẹ ya ara nyin si mimọ́ lati ba a jagun;
dide, ki ẹ si jẹ ki a goke li ọsan. Egbe ni
fun wa! nitori ọjọ nlọ, nitori ojiji ọjọ alẹ
nà jade.
5 Dide, ẹ jẹ ki a goke lọ li oru, ki a si
pa ãfin rẹ̀ run.
6 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi, ke igi lulẹ, ki ẹ si wà yàra ka Jerusale-
mu; eyi ni ilu nla ti a o bẹ̀wo; kìki ini-
nilara li o wà lãrin rẹ̀.
7 Bi isun ti itú omi rẹ̀ jade, bẽni o ntú
ìwa-buburu rẹ̀ jade: ìwa-ipa ati ìka li a
gbọ́ niwaju mi nigbagbogbo ninu rẹ̀ ani
aisan ati ọgbẹ́.

Digitized by Google

8 Gbọ́ ẹkọ́, Jerusalemu, ki ẹmi mi ki o
má ba lọ kuro lọdọ rẹ; ki emi má ba sọ ọ
di ahoro, ilẹ ti a kò gbe inu rẹ̀.
9 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, Jẹ
ki nwọn ki o pẽṣẹ iyokù Israeli bi àjara:
yi ọwọ rẹ pada bi aká-eso-ajara sinu agbọ̀n.
10 Tani emi o sọ fun, ti emi o kilọ fun
ti nwọn o si gbọ́? sa wò o, eti wọn jẹ alai-
kọla, nwọn kò si le fi iye si i: sa wò o, ọ̀rọ
Oluwa di ẹ̀gan si wọn, nwọn kò ni inu
didùn ninu rẹ̀.
11 Nitorina emi kún fun ikannu Oluwa,
ãrẹ̀ mu mi lati pa a mọra: tu u jade sori
ọmọde ni ita, ati sori ajọ awọn ọmọkọnrin
pẹlu: nitori a o mu bãle pẹlu aya rẹ̀ ni
igbekun, arugbo pẹlu ẹniti o ni ọjọ kikún
lori.
12 Ile wọn o di ti ẹlomiran, oko wọn ati
aya wọn lakopọ̀: nitori emi o nà ọwọ mi si
ori awọn olugbe ilẹ na, li Oluwa wi.
13 Lati kekere wọn titi de nla wọn,
gbogbo wọn li o fi ara wọn fun ojukokoro,
ati lati woli titi de alufa, gbogbo wọn ni
nṣe eke.
14 Nwọn si ti wo ọgbẹ ọmọbirin enia mi
fẹrẹ̀; nwọn wipe, Alafia! Alafia! nigbati
kò si alafia.
15 A mu itiju ba wọn, nitoriti nwọn ṣe
ohun irira: sibẹ nwọn kò tiju kan pẹ́lẹ,
pẹlupẹlu õru itiju kò mu wọn: nitorina
nwọn o ṣubu lãrin awọn ti o ṣubu: nigbati
emi ba bẹ̀ wọn wo, a o wó wọn lulẹ, li
Oluwa wi.
16 Bayi li Oluwa wi, ẹ duro li oju ọ̀na,
ki ẹ si wò, ki ẹ si bere oju-ọ̀na igbàni, ewo
li ọ̀na didara, ki ẹ si rin nibẹ, ẹnyin o si ri
isimi fun ọkàn nyin. Ṣugbọn nwọn wipe,
Awa kì yio rin.
17 Pẹlupẹlu mo fi oluṣọ sọdọ nyin, ti o
wipe, Ẹ fi eti si iro fère. Ṣugbọn nwọn
wipe, awa kì yio feti si i.
18 Nitorina, gbọ́, ẹnyin orilẹ-ède, ki ẹ
si mọ̀, ẹnyin ijọ enia, ohun ti o wà ninu
wọn!
19 Gbọ́, iwọ ilẹ! wò o, emi o mu ibi wá
si ori enia yi, ani eso iro inu wọn, nitori
nwọn kò fi eti si ọ̀rọ mi, ati ofin mi ni
nwọn kọ̀ silẹ.
20 Ere wo li o wà fun mi ninu turari
lati Ṣeba wá, ati ẽsu daradara lati ilẹ ti o
jina wá? ọrẹ sisun nyin kò ṣe inu-didun
mi, ẹbọ jijẹ nyin kò wù mi.
21 Nitorina, bayi li Oluwa wi, sa wò o,
emi o fi ohun idugbolu siwaju awọn enia
yi, ti baba ati awọn ọmọ yio jumọ ṣubu lù
wọn, aladugbo ati ọrẹ rẹ̀ yio ṣegbe.
22 Bayi li Oluwa wi, sa wò o, enia kan
ti ilu ariwa wá, ati orilẹ-ède nla kan yio ti
opin ilẹ aiye dide wá.
23 Nwọn di ọrun ati ọ̀kọ mu; onroro ni
nwọn, nwọn kò ni ãnu; ohùn wọn yio hó
bi okun; nwọn gun ẹṣin; nwọn si mura bi
ọkọnrin ti yio ja ọ logun, iwọ ọmọbirin
Sioni.
24 Awa ti gbọ́ òkiki eyi na: ọwọ wa di
rirọ, ẹ̀dun ti di wa mu, ati irora bi obirin
ti nrọbi.
25 Máṣe lọ si inu oko, bẽni ki o má si
rin oju ọ̀na na, nitori idà ọ̀ta, idagiri wà
yikakiri.
26 Iwọ, ọmọbirin enia mi, di ara rẹ ni
amure aṣọ-ọ̀fọ ki o si ku ẽru sara, ṣe ọ̀fọ bi
ẹniti nṣọ̀fọ fun ọmọ rẹ̀ nikanṣoṣo, pohùnre-
re kikoro: nitori afiniṣe-ijẹ yio ṣubu lù wa
lojiji.
27 Emi ti fi ọ ṣe ẹniti o ma dán ni wò,
odi alagbara lãrin enia mi, ki iwọ ki o le
mọ̀ ki o si le dan ọ̀na wọn wò.
28 Gbogbo nwọn ni agidi ọlọtẹ̀, ti nrin
kiri sọ̀rọ̀ ẹni lẹhin, idẹ ati irin ni nwọn;
abanijẹ ni gbogbo nwọn iṣe.
29 Ẹwìri joná, iná ti jẹ ojé, ẹniti nyọ ọ,
nyọ ọ lasan, a kò si ya enia buburu kuro.
30 Fàdaka bibajẹ ni enia yio ma pè wọn,
nitori Oluwa ti kọ̀ wọn silẹ.

## ORI 7.

Ọ̀RỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa
wá wipe:
2 Duro ni ẹnu ilẹkun ile Oluwa, ki o si
kede ọ̀rọ yi wipe, Gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, gbogbo
ẹnyin ti Juda ti ẹ wọ̀ ẹnu ilẹkun wọnyi
lati sin Oluwa.
3 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun
Israeli wi, tun ọ̀na ati ìwa nyin ṣe, emi o
si jẹ ki ẹnyin ma gbe ibi yi.
4 Ẹ máṣe gbẹkẹle ọ̀rọ eke, wipe: Tem-
pili Oluwa, Tempili Oluwa, Tempili Oluwa
ni eyi!
5 Nitori bi ẹnyin ba tun ọ̀na ati ìwa
nyin ṣe nitõtọ; ti ẹnyin ba ṣe idajọ otitọ
jalẹ, ẹnikini si ẹnikeji rẹ̀.
6 Ti ẹnyin kò ba si ṣẹ́ alejo ni iṣẹ́, alaini-
baba ati opó, ti ẹnyin kò si ta ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀
silẹ ni ibi yi, ti ẹnyin kò si rìn tọ ọlọrun
miran si ipalara nyin.
7 Nigbana ni emi o mu nyin gbe ibi yi,
ni ilẹ ti emi fi fun awọn baba nyin lai ati
lailai.
8 Sa wò o, ẹnyin gbẹkẹle ọ̀rọ eke, ti kò
ni ère.

Digitized by Google

9 Kohaṣepe, ẹnyin njale, ẹ npania, ẹ nṣe
panṣaga, ẹ nbura eke, ẹ nsun turari fun
Baali, ẹ si nrin tọ ọlọrun miran ti ẹnyin
kò mọ̀?
10 Ẹnyin si wá, ẹ si duro niwaju mi ni
ile yi, ti a fi orukọ mi pè! ẹnyin si wipe:
Gbà wa, lati ṣe gbogbo irira wọnyi?
11 Ile yi, ti ẹ fi orukọ mi pè, o ha di
iho olè li oju nyin? sa wò o, emi tikarami
ti ri i, li Oluwa wi.
12 Ẹ si lọ nisisiyi, si ibujoko mi, ti o
wà ni Ṣilo, ni ibi ti emi fi orukọ mi si li
àtetekọṣe, ki ẹ si ri ohun ti emi ṣe si i
nitori ìwa-buburu enia mi, Israeli.
13 Njẹ nisisiyi, nitori ẹnyin ti ṣe gbogbo
iṣẹ wọnyi, li Oluwa wi, ti emi si ba nyin
sọ̀rọ, ti emi ndide ni kutukutu ti mo si
nsọ, ṣugbọn ẹnyin kò gbọ́; ti emi si npè
nyin, ṣugbọn ẹnyin kò dahùn.
14 Nitorina li emi o ṣe si ile yi, ti a pè
ni orukọ mi, ti ẹ gbẹkẹle, ati si ibi ti emi
fi fun nyin, ati fun awọn baba nyin, gẹgẹ
bi emi ti ṣe si Ṣilo.
15 Emi o si ṣá nyin tì kuro niwaju mi,
gẹgẹ bi mo ti ṣá awọn arakọnrin nyin tì,
ani gbogbo iru-ọmọ Efraimu.
16 Nitorina máṣe gbadura fun enia yi,
bẽni ki o má si gbe igbe rẹ soke ati adura
fun wọn, bẽni ki o má ṣe rọ̀ mi: nitori
emi kì yio gbọ́ tirẹ.
17 Iwọ kò ha ri ohun ti nwọn nṣe ni ilu
Juda ati ni ita Jerusalemu?
18 Awọn ọmọ ko igi jọ, awọn baba nda
iná, awọn obirin npò akara lati ṣe akara
didùn fun ayaba-ọrun ati lati tú ẹbọ-ọrẹ
mimu jade fun ọlọrun miran, ki nwọn ki o
le rú ibinu mi soke.
19 Ibinu mi ni nwọn ha ru soke bi? li
Oluwa wi, kì ha ṣe si ara wọn fun ruduru-
du oju wọn?
20 Nitorina bayi li Ọlọrun Oluwa wi, sa
wò o, a o dà ibinu ati irunu mi si ibi yi,
sori enia ati sori ẹranko, ati sori igi igbo,
ati sori eso ilẹ, yio si jo, a kì o le pa iná rẹ̀.
21 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọ-
run Israeli wi, kó ẹbọ sisun nyin pẹlu ẹbọ
jijẹ nyin, ki ẹ si jẹ ẹran.
22 Nitori emi kò wi fun awọn baba
nyin, bẽni emi kò paṣẹ fun wọn ni ọjọ ti
mo mu wọn jade kuro ni ilẹ Egipti niti
ẹbọ sisun tabi ẹbọ jijẹ:
23 Ṣugbọn eyi ni mo paṣẹ fun wọn wipe,
Gba ohùn mi gbọ́, emi o si jẹ Ọlọrun nyin,
ẹnyin o si jẹ enia mi: ki ẹ si rin ni gbogbo
ọna ti mo ti paṣẹ fun nyin, ki o le dara fun
nyin.
24 Ṣugbọn nwọn kò gbọ́, bẽni nwọn kò
tẹ eti silẹ, nwọn si rin ni ìmọ ati agidi
ọkàn buburu wọn, nwọn si kọ̀ ẹ̀hin wọn kì
iṣe oju wọn si mi.
25 Lati ọjọ ti baba nyin ti ilẹ Egipti
jade wá titi di oni, emi ti rán gbogbo
iranṣẹ mi, awọn woli si nyin, lojojumọ emi
dide ni kutukutu, emi si rán wọn.
26 Sibẹ nwọn kò gbọ́ temi, bẽni nwọn
kò tẹti wọn silẹ, ṣugbọn, nwọn mu ọrun
le, nwọn ṣe buburu jù awọn baba wọn lọ.
27 Bi iwọ ba si wi gbogbo ọ̀rọ wọnyi
fun wọn, nwọn kì yio gbọ́ tirẹ: iwọ o si pè
wọn, ṣugbọn nwọn kì o da ọ lohùn.
28 Iwọ o si wi fun wọn pe: Eyi ni enia
na ti kò gba ohùn Oluwa Ọlọrun rẹ̀ gbọ́,
bẽni nwọn kò gba ẹkọ́: otitọ ṣègbe, a si ke
e kuro li ẹnu wọn.
29 Fá irun ori rẹ, ki o si sọ ọ nù, ki o si
sọkun lori oke: nitori Oluwa ti kọ̀ iran
ibinu rẹ̀ silẹ, o si ṣa wọn tì.
30 Nitori awọn ọmọ Juda ti ṣe buburu
niwaju mi, li Oluwa wi; nwọn ti gbe ohun
irira wọn kalẹ sinu ile ti a pe li orukọ mi,
lati ba a jẹ.
31 Nwọn si ti kọ́ ibi giga Tofeti, ti o wà
ni afonifoji ọmọ Hinnomu, lati sun awọn
ọmọkọnrin ati awọn ọmọbirin wọn ninu
iná; aṣẹ eyiti emi kò pa fun wọn, bẽni kò
si wá si inu mi.
32 Nitorina sa wò o, ọjọ mbọ̀, li Oluwa
wi, ti a kì o pe e ni Tofeti mọ, tabi afoni-
foji ọmọ Hinnomu, ṣugbọn a o pe e ni
afonifoji ipakupa: nitori nwọn o sin oku
ni Tofeti, titi àye kì yio si mọ.
33 Okú awọn enia yi yio di onjẹ fun
ẹiyẹ oju-ọrun, ati fun ẹranko ilẹ: ẹnikan
kì yio lé wọn kuro.
34 Emi o si mu ki ohùn inu-didun ki o
da kuro ni ilu Juda ati kuro ni ita Jerusa-
lemu ohùn ayọ̀, ohùn ọkọ-iyawo, ati ti
iyawo; nitori ilẹ na yio di ahoro.

## ORI 8.

LI akoko na, li Oluwa wi, ni nwọn o hú
egungun awọn ọba Juda ati egungun
awọn ijoye, egungun awọn alufa ati egun-
gun awọn woli, ati egungun awọn olugbe
Jerusalemu kuro ninu isà wọn:
2 Nwọn o si tẹ́ wọn siwaju õrùn ati
òṣupa ati gbogbo ogun ọrun, ti nwọn ti fẹ,
ti nwọn si ti sìn, awọn ti nwọn si rìn tọ̀
lẹhin, ti nwọn si wá, ti nwọn si foribalẹ
fun: a kì yio kó wọn jọ, bẽli a kì yio sin
wọn, nwọn o di àtan li oju ilẹ-aiye.
3 Awọn iyokù ti o kù ninu idile buburu

Digitized by Google

yi yio yan kikú jù yiyè lọ: ni ibi gbogbo
ti nwọn kù si, ti emi ti tì wọn jade si, li
Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
4 Iwọ o si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa
wi; enia le ṣubu li aidide mọ? tabi enia le
pada, ki o má tun yipada mọ?
5 Ẽṣe ti awọn enia Jerusalemu yi sọ ipa-
dasẹhin di ipẹhinda lailai? nwọn di ẹ̀tan
mu ṣinṣin, nwọn kọ̀ lati pada.
6 Mo tẹtilelẹ, mo si gbọ́, ṣugbọn nwọn
kò sọ̀rọ titọ: kò si ẹnikan ti o ronupiwada
buburu rẹ̀ wipe, kili emi ṣe? gbogbo nwọn
yipo li ọ̀na wọn, bi akọ-ẹṣin ti nsare gburu
sinu ogun.
7 Lõtọ ẹiyẹ àkọ li oju-ọrun mọ̀ akoko rẹ̀,
àdaba ati ẹiyẹ lekeleke pẹlu alapandẹ̀dẹ ṣọ́
igba wiwá wọn; ṣugbọn enia mi kò mọ̀
idajọ Oluwa.
8 Bawo li ẹnyin ṣe wipe, Ọlọgbọ́n ni wa,
ati ofin Oluwa mbẹ lọdọ wa? sa wò o nitõ-
tọ! kalamu eke awọn akọwe ti sọ ofin di
eke.
9 Oju tì awọn ọlọgbọ́n, idamu ba wọn a
si mu wọn: sa wò o, nwọn ti kọ̀ ọ̀rọ Olu-
wa! ọgbọ́n wo li o wà ninu wọn?
10 Nitorina ni emi o fi aya wọn fun ẹlo-
miran, ati oko wọn fun awọn ti yio gbà
wọn: nitori gbogbo wọn, lati ẹni kekere
titi o fi de ẹni-nla, fi ara wọn fun ojuko-
koro, lati woli titi de alufa, gbogbo wọn
nṣe ẹ̀tan.
11 Nitoripe nwọn ti wo ipalara ọmọbi-
rin enia mi fẹrẹ̀ wipe, Alafia! Alafia!
nigbati alafia kò si.
12 Itiju yio ba wọn nitori nwọn ti ṣe
ohun irira, sibẹ nwọn kò tiju, bẽni õru itiju
kò mu wọn, nitorina ni nwọn o ṣe ṣubu
lãrin awọn ti o ṣubu; ni igba ibẹ̀wo wọn,
a o si wó wọn lulẹ, li Oluwa wi.
13 Ni kiká emi o ká wọn jọ, li Oluwa
wi, eso-àjara kì yio si mọ lori ajara, tabi
eso-ọ̀pọtọ lori igi ọ̀pọtọ, ewe rẹ̀ yio si rẹ̀;
nitorina ni emi o yàn awọn ti yio kọja lọ
lori rẹ̀.
14 Ẽṣe ti awa joko jẹ? ẹ ko ara nyin jọ,
ki ẹ si jẹ ki a wọ̀ inu ilu olodi, ki a si dakẹ
sibẹ: nitori Oluwa Ọlọrun wa, ti mu wa
dakẹ, o si fun wa ni omi orõro lati mu,
nitori ti awa ṣẹ̀ si Oluwa.
15 Awa reti alafia, ṣugbọn kò si ireti
kan, ati igba didá ara, si kiye si i, idamu!
16 Lati Dani ni a gbọ́ fifọn imu ẹṣin rẹ̀;
gbogbo ilẹ warìri fun iro yiyan akọ-ẹṣin rẹ̀;
nwọn si de, nwọn si jẹ ilẹ run, ati eyi ti
mbẹ ninu rẹ̀: ilu ati awọn ti ngbe inu rẹ̀,
17 Sa wò o, emi o ran ejo, ejo gunte si
ãrin nyin, ti kì yio gbọ́ ituju, nwọn o si
bu nyin jẹ, li Oluwa wi.
18 Emi iba le tù ara mi ninu, ninu
ikãnu mi? ọkàn mi daku ninu mi!
19 Sa wò o, ohùn ẹkún ọmọbirin enia
mi, lati ilẹ jijina wá, Kò ha si Oluwa ni
Sioni bi? ọba rẹ̀ kò ha si ninu rẹ̀? ẽṣe ti
nwọn fi ere gbigbẹ ati ohun asan àjeji mu
mi binu?
20 Ikore ti kọja, ẹ̀run ti pari, a kò si
gba wa la!
21 Nitori ipalara ọmọbirin enia mi li a
ṣe pa mi lara; emi ṣọ̀fọ, iyanu si di mi mu.
22 Kò ha si ojiya ikunra ni Gileadi,
onișegun kò ha si nibẹ? ẽṣe ti a kò fi ọ̀ja
dì ọgbẹ́ ọmọbirin enia mi.

## ORI 9.

ORI mi iba jẹ omi, ati oju mi iba jẹ ori-
sun omije, ki emi le sọkun lọsun ati
loru fun awọn ti a pa ninu ọmọbirin enia
mi!
2 A! emi iba ni buka ero ni iju, ki emi
ki o le fi enia mi silẹ, ki nlọ kuro lọdọ
wọn! nitori gbogbo nwọn ni panṣaga, ajọ
alarekereke enia ni nwọn.
3 Nwọn si fà ahọn wọn bi ọrun fun eke;
ṣugbọn nwọn kò ṣe akoso fun otitọ lori ilẹ,
nitoripe nwọn ti inu buburu lọ si buburu
nwọn kò si mọ̀ mi, li Oluwa wi.
4 Ẹ mã ṣọra, olukuluku nyin lọdọ ala-
dugbo rẹ̀, ki ẹ má si gbẹkẹlẹ arakọnrin
karakọnrin: nitoripe olukuluku arakọnrin
fi arekereke ṣẹtan patapata, ati olukuluku
aladugbo nsọ̀rọ ẹnilẹhin.
5 Ẹnikini ntàn ẹnikeji rẹ̀ jẹ, nwọn kò si
sọ otitọ: nwọn ti kọ́ ahọn wọn lati ṣeke,
nwọn si ti ṣe ara wọn lãrẹ lati ṣe aiṣedede.
6 Ibugbe rẹ mbẹ lãrin ẹ̀tan; nipa ẹ̀tan
nwọn kọ̀ lati mọ̀ mi, li Oluwa wi.
7 Nitorina bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi, sa wò o, emi o yọ́ wọn, emi o si
dán wọn wò, nitori kili emi o ṣe fun ọmọ-
birin enia mi.
8 Ahọn wọn dabi ọfa ti a ta, o nsọ ẹ̀tan,
ẹnikini nfi ẹnu rẹ̀ sọ alafia fun ẹnikeji rẹ̀,
ṣugbọn li ọkàn rẹ̀ o ba dè e.
9 Emi kì yio ha bẹ̀ wọn wò nitori nkan
wọnyi? li Oluwa wi, ọkàn mi kì yio ha
gbẹsan lara orilẹ-ède bi iru eyi?
10 Fun awọn oke-nla ni emi o gbe ẹkún
ati ohùnrere soke, ati ẹkún irora lori papa
oko aginju wọnnì, nitoriti nwọn jona, ẹni-
kan kò le kọja nibẹ bẽni a kọ̀ gbọ́ ohùn
ẹran-ọsin, lati ẹiyẹ oju-ọrun titi de ẹranko
ti sa kuro, nwon ti lọ.

Digitized by Google

11 Emi o sọ Jerusalemu di okiti àlapa,
ati iho awọn ikõko, emi o si sọ ilu Juda di
ahoro, laini olugbe.
12 Tani enia na ti o gbọ́n, ti o moye yi?
ati tani ẹniti ẹnu Oluwa ti sọ fun, ki o ba
le kede rẹ̀, pe: kili o ṣe ti ilẹ fi ṣegbe, ti o
si sun jona bi aginju, ti ẹnikan kò kọja
nibẹ?
13 Oluwa si wipe, nitoriti nwọn ti kọ̀
ofin mi silẹ ti mo ti gbe kalẹ niwaju wọn,
ti nwọn kò si gbà ohùn mi gbọ́, bẽni nwọn
kò si rin ninu rẹ̀.
14 Ṣugbọn nwọn ti rin nipa agidi ọkàn
wọn ati nipasẹ Baalimu, ti awọn baba wọn
kọ́ wọn:
15 Nitorina bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun, Ọlọrun Israeli wi; sa wò o, awọn
enia yi pãpa ni emi o fi wahala bọ́, emi o
si mu wọn mu omi orõro.
16 Emi o si tú wọn ka ninu awọn kefe-
ri, ti awọn tikarawọn ati baba wọn kò mọ
ri, emi o si rán idà si wọn titi emi o fi run
wọn.
17 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ọgun wi, Ẹ
kiye si i, ki ẹ si pe awọn obirin ti nṣọfọ, ki
nwọn wá; ẹ si ranṣẹ pè awọn obirin ti o
moye, ki nwọn wá.
18 Ki nwọn ki o si yara, ki nwọn po-
hùnrere ẹkun fun wa, ki oju wa ki o le sun
omije ẹkun, ati ki ipenpeju wa le tu omi
jade.
19 Nitori a gbọ́ ohùn ẹkun lati Sioni,
pe, A ti pa wa run to! awa dàmu jọjọ,
nitoriti a kọ̀ ilẹ yi silẹ, nitoriti ibugbe wa
ti wa jade.
20 Njẹ ẹnyin obirin, ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, ẹ
jẹ ki eti nyin gbọ́ ọ̀rọ ẹnu rẹ̀, ki ẹ si kọ́
ọmọbirin nyin ni ẹkun, ati ki olukuluku
obirin ki o kọ́ aladugbo rẹ̀ ni arò.
21 Nitori iku ti de oju ferese wa, o ti
wọ̀ inu ãfin wa, lati ke awọn ọmọ-ọmu ku-
ro ni ita, ati awọn ọmọde-kọnrin kuro ni
igboro.
22 Sọ pe, Bayi li Oluwa wi, Okú enia
yio ṣubu bi àtan li oko, ati bi ibukunwọ
lẹhin olukore, ti ẹnikan ko kojọ.
23 Bayi li Oluwa wi, ki ọlọgbọ́n ki o má
ṣogo nitori ọgbọ́n rẹ̀, bẽni ki alagbara ki o
má ṣogo nitori agbara rẹ̀, ki ọlọrọ̀ ki o má
ṣogo nitori ọrọ̀ rẹ̀.
24 Ṣugbọn ki ẹnikẹni ti yio ba ma ṣogo,
ki o ṣe e ninu eyi pe: on ni oye, on si mọ̀
mi; pe, Emi li Oluwa ti nṣe ãnu ati idajọ
ati ododo li aiye: nitori inu mi dùn ninu
ohun wọnyi, li Oluwa wi.
25 Sa wò o, ọjọ mbọ̀, li Oluwa wi, ti
emi o jẹ gbogbo awọn ti a kọ ni ilà pẹlu
awọn alaikọla ni ìya;
26 Egipti ati Juda ati Edomu, ati awọn
ọmọ Ammoni ati Moabu, pẹlu gbogbo awọn
ti ndá òṣu, ti ngbe aginju: nitori alaikọla
ni gbogbo orilẹ-ède yi, ṣugbọn gbogbo ile
Israeli jẹ alaikọla ọkàn.

## ORI 10.

EGBỌ́ ọ̀rọ ti Oluwa sọ fun nyin, ẹnyin
ile Israeli:
2 Bayi li Oluwa wi, Ẹ máṣe kọ́ ìwa awọn
keferi, ki àmi ọrun ki o má si dãmu nyin,
nitoripe, nwọn ndamu awọn orilẹ-ède.
3 Nitori asan ni ilana awọn orilẹ-ède;
nitori igi ti a ke lati igbo ni iṣẹ ọwọ onișọ-
na ati ti ãke.
4 Nwọn fi fádaka ati wura ṣe e lọṣọ,
nwọn fi iṣo ati olù dì i mu, ki o má le mì.
5 Nwọn nàro bi igi ọpẹ, ṣugbọn nwọn
kò fọhùn: gbigbe li a ngbe wọn, nitori
nwọn kò le rin. Má bẹ̀ru wọn; nitori
nwọn kò le ṣe buburu, bẽli ati ṣe rere, kò
si ninu wọn.
6 Kò si ẹnikan ti o dabi Iwọ Oluwa!
iwọ tobi, orukọ rẹ si tobi ni agbara!
7 Tani kì ba bẹ̀ru rẹ, Iwọ Ọba orilẹ-ède?
nitori tirẹ ni o jasi; kò si ninu awọn ọlọ-
gbọ́n orilẹ-ède, ati gbogbo ijọba wọ̀n, kò si
ẹniti o dabi Iwọ!
8 Ṣugbọn nwọn jumọ ṣe ope ati aṣiwere;
ìti igi ni ẹkọ́ ohun asan.
9 Fadaka ti a fi ṣe awo ni a mu lati
Tarṣiṣi wá, ati wura lati Upasi wá, iṣẹ oni-
ṣọna, ati lọwọ alagbẹdẹ: alaro ati elese
aluko ni aṣọ wọn: iṣẹ ọlọgbọ́n ni gbogbo
wọn.
10 Ṣugbọn Oluwa, Ọlọrun otitọ ni, on
ni Ọlọrun alãye, ati Ọba aiyeraiye! aiye
yio warìri nigbati o ba binu, orilẹ-ède kì
yio le duro ni ibinu rẹ̀.
11 Bayi li ẹnyin o wi fun wọn pe:
Awọn ọlọrun ti kò da ọrun on aiye, awọn
na ni yio ṣegbe loju aiye, ati labẹ ọrun
wọnyi.
12 On ti da aiye nipa agbara rẹ̀, on ti
pinnu araiye nipa ọgbọ́n rẹ̀, o si nà awọn
ọrun nipa oye rẹ̀.
13 Nigbati o ba sán ãrá, ọ̀pọlọpọ omi ni
mbẹ loju-ọrun, o si jẹ ki kũku rú soke lati
opin aiye; o da mànamana fun òjo, o si
mu ẹfũfu jade lati inu iṣura rẹ̀ wá.
14 Aṣiwere ni gbogbo enia nitori oye kò
si: oju tì olukuluku alagbẹdẹ niwaju ere
rẹ̀, nitori ère didà rẹ̀ eke ni, kò si sí ẹmi
ninu rẹ̀.



Digitized by Google

15 Asan ni nwọn, ati iṣẹ iṣina: nigba ibẹwo wọn nwọn o ṣègbe.

16 Ipin Jakobu kò si dabi wọn: nitori on ni iṣe Ẹlẹda ohun gbogbo; Israeli si ni ẹya ijogun rẹ̀: Oluwa awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀.

17 Ko ẹrù rẹ kuro ni ilẹ na, Iwọ olugbe ilu ti a dotì.

18 Nitori bayi li Oluwa wi, sa wò o, emi o gbọ̀n awọn olugbe ilẹ na nù lẹ̀kan yi, emi o si pọ̀n wọn loju, ki nwon ki o le ri i.

19 Egbe ni fun mi nitori ipalara mi! ọgbẹ mi pọ̀: ṣugbọn mo wipe, nitõtọ ìya mi ni eyi, emi o si rù u.

20 Agọ mi bajẹ, gbogbo okùn mi si ja: awọn ọmọ mi ti fi mi silẹ lọ, nwọn kò sí mọ́, kò si ẹnikan ti yio nà agọ mi mọ, ti yio si ta aṣọ ikele mi.

21 Nitori awọn oluṣọ agutan ti di ope, nwọn kò si wá Oluwa: nitorina nwọn kì yio ri rere, gbogbo agbo wọn yio si tuka.

22 Sa wò o, ariwo igbe ti de, ati irukerudo nla lati ilẹ ariwa wá, lati sọ ilu Juda di ahoro, ati iho ọwawa.

23 Oluwa! emi mọ̀ pe, ọ̀na enia kò si ni ipa ara rẹ̀: kó si ni ipá enia ti nrin, lati tọ́ iṣisẹ rẹ̀.

24 Oluwa kilọ fun mi, ṣugbon ni idajọ ni, ki o máṣe ni ibinu rẹ, ki iwọ ki o má sọ mi di asan.

25 Tu ibinu rẹ si ori awọn orilẹ-ède, ti kò mọ̀ ọ, ati sori awọn idile ti kò ke pè orukọ rẹ, nitoriti nwọn ti jẹ Jakobu run, nwọn si gbe e mì, nwọn si pa a run tan, nwọn si sọ ibugbe rẹ̀ di ahoro.

## ORI 11.

ỌRỌ ti o ti ọdọ Oluwa wá sọdọ Jeremiah wipe;

2 Ẹ gbọ́ ọ̀rọ majẹmu yi, ki ẹ si sọ fun awọn enia Juda ati awọn olugbe Jerusalemu,

3 Ki iwọ ki o si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi; Ifibu ni oluwarẹ̀ ti kò ba gbà ọ̀rọ majẹmu yi gbọ́,

4 Ti mo pa li aṣẹ fun awọn baba nyin, li ọjọ ti mo mu wọn ti ilẹ Egipti jade, lati inu ileru irin wipe, Gbà ohùn mi gbọ́, ki ẹ si ṣe gẹgẹ bi emi ti paṣẹ fun nyin: bẽni ẹnyin o jẹ ẹnia mi, emi o si jẹ Ọlọrun nyin:

5 Ki emi ki o le mu ileri mi ṣẹ, ti mo ti bura fun awọn baba nyin, lati fun wọn ni ilẹ ti nṣàn fun wara ati fun oyin, gẹgẹ bi o ti ri li oni: mo si dahùn mo si wipe, Amin, Oluwa!

6 Oluwa si wi fun mi pe, Kede gbogbo ọ̀rọ wọnyi ni ilu Juda ati ni ita Jerusalemu wipe, Ẹ gbọ́ ọ̀rọ majẹmu yi ki ẹ si ṣe wọn.

7 Nitori ni kikilọ mo kilọ fun awọn baba nyin lati ọjọ ti mo ti mu wọn wá lati ilẹ Egipti, titi di oni, emi si nyara kilọ fun wọn, mo si nsọ wipe, Ẹ gbà ohùn mi gbọ́.

8 Sibẹsibẹ nwọn kò gbọ́, nwọn kò tẹti silẹ, nwọn si rìn, olukuluku wọn ni agidi ọkàn buburu wọn: nitorina emi o mu gbogbo ọ̀rọ majẹmu yi wá sori wọn, ti mo paṣẹ fun wọn lati ṣe; nwọn kò si ṣe e.

9 Oluwa si wi fun mi pe, A ri ìditẹ lãrin awọn ọkọnrin Juda ati lãrin awọn olugbe Jerusalemu.

10 Nwọn yipada si ẹ̀ṣẹ iṣaju awọn baba wọn ti o kọ̀ lati gbọ́ ọ̀rọ mi; awọn wọnyi si tọ̀ ọlọrun miran lẹhin lati sìn wọn: ile Israeli ati ile Juda ti dà majẹmu mi ti mo ba awọn baba wọn dá.

11 Nitorina, bayi li Oluwa wi, sa wò o, Emi o mu ibi wá sori wọn, ti nwọn kì yio le yẹba fun: bi nwọn tilẹ ke pè mi, emi kì yio fetisi igbe wọn.

12 Jẹ ki ilu Juda ati awọn olugbe Jerusalemu ki o lọ, ki nwọn ki o si ke pe awọn ọlọrun ti nwọn sun turari fun, ṣugbọn lõtọ nwọn kì yio le gba wọn ni igba ipọnju wọn.

13 Nitori bi iye ilu rẹ, bẽni iye ọlọrun rẹ, iwọ Juda, ati bi iye ita Jerusalemu, bẽni iye pẹpẹ ti ẹnyin ti tẹ́ fun ohun itìju nì, pẹpẹ lati sun turari fun Baali.

14 Nitorina máṣe gbadura fun awọn enia yi, bẽni ki o má si ṣe gbe ohùn ẹkun tabi ti adura soke fun wọn, nitori emi kì yio gbọ́ ni igba ti nwọn ba kigbe pè mi, ni wakati wahala wọn.

15 Kini olufẹ mi ni iṣe ni ile mi? nigbati nwọn nṣe buburu pupọ bayi? adura on ẹran mimọ́ ha le mu ibi kọja kuro lọdọ rẹ? bi o ba ri bayi nigbana jẹ ki inu rẹ ki o dùn.

16 Oluwa pè orukọ rẹ ni igi Olifi tutu, didara, eleso rere: ṣugbon nisisiyi o fi ariwo irọkẹkẹ nla dá iná lara rẹ̀, ẹka rẹ̀ li o si faya.

17 Nitori Oluwa awọn ọmọ-ogun, ti o gbìn ọ, ti sọ̀rọ ibi si ọ, nitori buburu ile Israeli, ati ile Juda, ti nwọn ti ṣe si ara wọn lati ru ibinu mi soke ni sisun turari fun Baali.

18 Oluwa si ti mu mi mọ̀, emi si mọ̀: nigbana ni iwọ fi iṣe wọn hàn mi.

Digitized by Google

19 Ani mo dabi ọdọ-agutan ti o mọ̀ oju ile, ti a mu wá fun pipa: emi kò si mọ̀ pe, nwọn ti pinnu buburu si mi wipe: Jẹ ki a ke igi na pẹlu eso rẹ̀, ki a si ke e kuro ni ilẹ alãye, ki a máṣe ranti orukọ rẹ̀ mọ.

20 Ṣugbọn Oluwa awọn ọmọ-ogun, onidajọ otitọ ti ndan aiya ati inu wò, emi o ri igbẹsan rẹ lori wọn: nitori iwọ ni mo fi ọ̀ran mi le lọwọ.

21 Nitorina bayi li Oluwa wi, niti enia Anatoti ti o nwá ẹmi rẹ, ti nwipe, Máṣe sọ asọtẹlẹ li orukọ Oluwa, ki iwọ ki o má ba kú nipa ọwọ wa.

22 Nitorina bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, wò o, emi o bẹ̀ wọn wo, awọn ọdọmọkọnrin o ti ọwọ idà kú, ọmọ wọn ọkọnrin ati ọmọ wọn obirin yio kú nipa iyàn:

23 Ẹnikan kì yio kù ninu wọn: nitori emi o mu ibi wá sori awọn enia Anatoti, ani ọdun ìbẹwo wọn.

## ORI 12.

ALARE ni iwọ, Oluwa, nigbati mo mba ọ wijọ: sibẹ, jẹ ki emi ba ọ sọ ti ọ̀ran idajọ: ẽtiṣe ti ãsiki mbẹ ni ọ̀na enia buburu, ti gbogbo awọn ti nṣe ẹ̀tan jẹ alailewu.

2 Iwọ ti gbìn wọn, nwọn si ti ta gbòngbo: nwọn dagba, nwọn si nso eso: iwọ sunmọ ẹnu wọn, o si jìna si ọkàn wọn.

3 Ṣugbọn iwọ, Oluwa, mọ̀ mi: iwọ ri mi, o si dan ọkàn mi wò bi o ti ri si ọ: pa wọn mọ bi agutan fun pipa, ki o si yà wọn sọtọ fun ọjọ pipa.

4 Yio ti pẹ to ti ilẹ yio fi ma ṣọ̀fọ, ati ti ewe igbẹ gbogbo yio rẹ̀ nitori ìwa-buburu awọn ti mbẹ ninu rẹ̀? ẹranko ati ẹiyẹ nṣòfò nitori ti nwọn wipe, on kì o ri ẹ̀hin wa.

5 Bi iwọ ba ba ẹlẹsẹ rìn, ti ãrẹ si mu ọ, iwọ o ha ti ṣe ba ẹlẹṣin dije? ati pẹlu ni ilẹ alafia, bi iwọ ba ni igbẹkẹle, kini iwọ o ṣe ninu ẹkún odò Jordani?

6 Nitori pẹlupẹlu, awọn arakọnrin rẹ, ati ile baba rẹ, awọn na ti hùwa ẹ̀tan si ọ, lõtọ, awọn na ti ho le ọ: Má gbẹkẹle wọn, bi nwọn tilẹ ba ọ sọ̀rọ daradara.

7 Emi ti kọ̀ ile mi silẹ, mo ti fi ogún mi silẹ; mo ti fi olufẹ ọ̀wọn ọkàn mi le ọta rẹ̀ lọwọ.

8 Ogún mi di kiniun ninu igbo fun mi; on kigbe soke si mi; nitorina ni mo ṣe korira rẹ̀.

9 Ogún mi di ẹranko ọ̀wawa fun mi, ẹranko yi i kakiri, ẹ lọ, ẹ ko gbogbo ẹran igbẹ jọ pọ̀, ẹ mu wọn wá jẹ.

10 Ọpọlọpọ oluṣọ-agutan ba ọgba-ajara mi jẹ, nwọn tẹ ipin oko mi mọlẹ labẹ ẹsẹ wọn, nwọn ti sọ ipin oko mi ti mo fẹ di aginju ahoro.

11 Nwọn ti sọ ọ di ahoro, o ṣọ̀fọ fun mi bi ahoro: gbogbo ilẹ ti di ahoro, nitori ti kò si ẹnikan ti o rò li ọkàn rẹ̀.

12 Awọn abanijẹ ti gori gbogbo ibi giga wọnni ni ọ̀dan, nitori idà Oluwa yio pa lati ikangun de ikangun ekeji ilẹ na, alafia kò si fun gbogbo alãye.

13 Nwọn ti gbin alikama, ṣugbọn nwọn o ka ẹ̀gun, nwọn ti fi irora ẹ̀dun mu ara wọn, ṣugbọn nwọn kì yio ri anfani: ki oju ki o tì nyin nitori ère nyin, nitori ibinu gbigbona Oluwa.

14 Bayi li Oluwa wi si gbogbo awọn aladugbo buburu mi ti nwọn fi ọwọ kan ogún mi ti mo ti mu enia mi, Israeli, jogun. Sa wò o, emi o fa wọn tu kuro ni ilẹ wọn, emi o si fà ile Juda tu kuro larin wọn.

15 Yio si ṣe, nigba ti emi o ti fà wọn tu kuro tan, emi o pada, emi o si ni iyọ́nu si wọn, emi o si tun mu wọn wá, olukuluku wọn, si ogún rẹ̀, ati olukuluku si ilẹ rẹ̀.

16 Yio si ṣe, bi nwọn ba ṣe ãpọn lati kọ́ ìwa enia mi, lati fi orukọ mi bura pe, Oluwa mbẹ; gẹgẹ bi nwọn ti kọ́ enia mi lati fi Baali bura; nigbana ni a o gbe wọn ró lãrin enia mi.

17 Ṣugbọn bi nwọn kì o gbọ́, emi o fà orilẹ-ède na tu patapata; emi o si pa wọn run, li Oluwa wi.

## ORI 13.

BAYI li Oluwa wi fun mi pe: Lọ, ki o si rà àmure aṣọ ọgbọ̀, ki o si dì i mọ ẹgbẹ rẹ, ki o má si fi i sinu omi.

2 Bẽ li emi si rà àmure na, gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, emi si dì i mọ ẹgbẹ mi.

3 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wa lẽkeji wipe:

4 Mu amure ti iwọ ti rà, ti o wà li ẹgbẹ rẹ, ki o si dide, lọ si odò Ferate, ki o si fi i pamọ nibẹ, ninu pàlapála okuta.

5 Bẽni mo lọ, emi si fi i pamọ leti odò Ferate, gẹgẹ bi Oluwa ti paṣẹ fun mi.

6 O si ṣe lẹhin ọjọ pupọ, Oluwa wi fun mi pe, Dide, lọ si odò Ferate, ki o si mu amure nì jade, ti mo paṣẹ fun ọ lati fi pamọ nibẹ.

7 Mo si lọ si odò Ferate, mo si walẹ̀, mo

Digitized by Google

si mu àmure na jade kuro ni ibi ti emi ti fi
i pamọ si, sa wò o, àmure na di hihù, kò
si yẹ fun ohunkohun.
8 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá
wipe,
9 Bayi li Oluwa wi, Gẹgẹ bi eyi na ni
emi o bà igberaga Juda jẹ, ati igberaga nla
Jerusalemu.
10 Awọn enia buburu yi, ti o kọ̀ lati
gbọ̀ ọ̀rọ mi, ti nrin ni agidi ọkàn wọn, ti o
si nrin tọ̀ awọn ọlọrun miran, lati sìn wọn
ati lati foribalẹ fun wọn, yio si dabi àmure
yi, ti kò yẹ fun ohunkohun.
11 Nitori bi amure iti lẹ̀ mọ ẹgbẹ enia,
bẽni mo ṣe ki gbogbo ile Israeli ati gbogbo
ile Juda ki o lẹ̀ mọ mi lara, li Oluwa wi,
ki nwọn ki o le jẹ enia mi, ati orukọ ati
ogo, ati iyìn, ṣugbọn nwọn kò fẹ igbọ́.
12 Nitorina ki iwọ ki o sọ ọ̀rọ yi fun
wọn pe; Bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi,
Gbogbo igo ni a o fi ọti-waini kún: nwọn
o si wi fun ọ pe, A kò ha mọ̀ nitõtọ pe,
gbogbo igo ni a o fi ọti-waini kún?
13 Nigbana ni iwọ o sọ fun wọn pe,
Bayi li Oluwa wi, sa wò o, emi o fi imuti-
para kún gbogbo olugbe ilẹ yi, ani awọn
ọba ti o joko lori itẹ Dafidi, awọn alufa
ati awọn woli, pẹlu gbogbo awọn olugbe
Jerusalemu.
14 Emi o tì ekini lu ekeji, ani awọn
baba ati awọn ọmọkọnrin pọ̀, li Oluwa wi:
emi kì yio dariji, bẽni emi kì o ṣãnu, emi
kì yio ṣe iyọ́nu, lati má pa wọn run.
15 Ẹ gbọ́, ki ẹ si fi eti silẹ; ẹ má ṣe
gberaga: nitori ti Oluwa ti sọ̀rọ.
16 Ẹ fi ogo fun Oluwa Ọlọrun nyin, ki o
to mu òkunkun wá, ati ki o to mu ẹsẹ nyin
tase lori oke ṣiṣu wọnni, ati nigbati ẹnyin
si nreti imọlẹ, on o sọ ọ di ojiji ikú, o si ṣe
e bi òkunkun biribiri.
17 Ṣugbọn bi ẹnyin kì o gbọ́, ọkàn mi
yio sọkun ni ibi ikọkọ, nitori igberaga na,
oju mi yio sọkun kikan, yio sun omije
pẹrẹpẹ̀rẹ, nitori ti a kó agbo Oluwa lọ ni
igbekun.
18 Sọ fun ọba ati fun ayaba pe, Ẹ rẹ̀ ara
nyin silẹ, ẹ joko silẹ, nitori ade ogo nyin
bọ̀ si ilẹ lati ori nyin.
19 Ilu gusun wọnni ni a o se mọ kò si
ẹnikan ti yio ṣi wọn: a o kó Juda, lọ ni
igbekun gbogbo rẹ̀, a o kó wọn lọ patapata
ni igbekun.
20 Gbe oju nyin soke, ki ẹ si wo awọn ti
mbọ̀ lati ariwa! nibo ni agbo-ẹran nì wà,
ti a fi fun ọ, agbo-ẹran rẹ daradara?
21 Kini iwọ o wi, nigbati on o fi awọn
ti iwọ ti kọ́ lati ṣe korikosun rẹ jẹ olori lori
rẹ, irora kì yio ha mu ọ bi obirin ti nrọbi?
22 Bi iwọ ba si wi ninu ọkàn rẹ pe, Ẽṣe
ti nkan wọnyi ṣe wá sori mi? Nitori ti
ọ̀pọlọpọ ẹ̀ṣẹ rẹ ni a ṣe ká aṣọ rẹ soke, ti a si
fi agbara fi gigisẹ rẹ hàn ni ihoho.
23 Ara Etiopia le yi àwọ rẹ̀ pada, tabi
ẹkùn le yi ilà ara rẹ̀ pada? bẽni ẹnyin pẹlu
iba le ṣe rere, ẹnyin ti a kọ́ ni ìwa buburu?
24 Nitorina ni emi o tú wọn ka bi iyan-
gbo ti nkọja lọ niwaju afẹfẹ aginju.
25 Eyi ni ipin rẹ, apakan òṣuwọn rẹ
lọwọ mi, li Oluwa wi: nitori iwọ ti gbàgbe
mi, ti o si gbẹkẹle eke.
26 Nitorina emi o ka aṣọ iṣẹti rẹ loju rẹ,
ki itiju rẹ ki o le hàn sode.
27 Emi ti ri panṣaga rẹ, ati yiyan rẹ bi
ẹṣin, buburu ìwa-agbere rẹ, ati ìwa irira rẹ
lori oke ati ninu oko. Egbe ni fun ọ, iwọ
Jerusalemu! iwọ kò le di mimọ́, yio ha ti
pẹ to!

## ORI 14.

EYI li ọ̀rọ Oluwa ti o tọ̀ Jeremiah wá
sipa ti ọdá.
2 Juda kãnu ati ẹnu-bode rẹ̀ wọnnì si
jõro, nwọn dudu de ilẹ; igbe Jerusalemu
si ti goke.
3 Awọn ọlọla wọn si ti rán awọn ọmọ
wẹrẹ lọ si odò: nwọn wá si kanga, nwọn
kò ri omi; nwọn pada pẹlu agbè wọn lofo,
oju tì wọn, idãmu mu wọn, nwọn si bo ori
wọn.
4 Nitori ilẹ, ti ndãmu gidigidi, nitoriti
òjo kò si ni ilẹ, oju tì awọn àgbẹ, nwọn bo
ori wọn.
5 Lõtọ abo-àgbọnrin pẹlu ni papa bimọ,
o fi i silẹ nitori ti kò si koriko.
6 Ati awọn kẹtẹkẹtẹ-igbẹ duro lori oke
wọnni, nwọn fọn imu si ẹfũfu bi ikõko, oju
wọn rẹ̀ nitoriti kò si koriko.
7 Oluwa, bi ẹ̀ṣẹ wa ti jẹri si wa to nì, ṣe
atunṣe nitori orukọ rẹ: nitoriti ipẹhinda
wa pọ̀; si ọ li awa ti ṣẹ̀.
8 Iwọ, ireti Israeli, olugbala rẹ̀ ni waka-
ti ipọnju! ẽṣe ti iwọ o dabi alejo ni ilẹ ati
bi èro ti o pa agọ lati sùn?
9 Ẽṣe ti iwọ o dabi ẹniti o dãmu, bi ọkọn-
rin akọni ti kò le ràn ni lọwọ? sibẹ iwọ,
Oluwa, mbẹ li ãrin wa, a si npè orukọ rẹ
mọ wa, má fi wa silẹ.
10 Bayi li Oluwa wi fun awọn enia yi,
bayi ni nwọn ti fẹ lati rò kiri, nwọn kò dá
ẹsẹ wọn duro; Oluwa kò si ni inu-didun
ninu wọn: yio ranti aiṣedẽde wọn nisisiyi,
yio si bẹ ẹ̀ṣẹ wọn wò.

Digitized by Google

11 Nigbana li Oluwa wi fun mi pe,
Máșe gbadura fun awọn enia yi fun rere.
12 Nigbati nwọn ba gbãwẹ, emi kì yio
gbọ́ ẹ̀bẹ wọn ; nigbati nwọn ba ru ẹbọ-ọrẹ
sisun ati ẹbọ-ọrẹ, inu mi kì o dùn si wọn:
șugbọn emi o fi idà, ati ìyan, ati ajakalẹ-
àrun pa wọn run.
13 Emi si wipe, Oluwa Ọlọrun, sa wò o,
awọn woli wi fun wọn pe ; Ẹnyin kì yio
ri idà, bẽli ìyan kì yio de si nyin ; șugbọn
emi o fun nyin ni alafia otitọ ni ibi yi.
14 Nigbana ni Oluwa wi fun mi pe,
awọn woli nsọ asọtẹlẹ eke li orukọ mi;
emi kò rán wọn, bẽni emi kò pașẹ fun wọn,
emi kò si sọ̀rọ kan fun wọn, iran eke, afọșẹ,
ati ohun asan, ati ẹ̀tan inu wọn, ni awọn
wọnyi sọtẹlẹ fun nyin.
15 Nitorina bayi li Oluwa wi niti awọn
woli ti nsọ asọtẹlẹ li orukọ mi, ti emi kò
rán ; sibẹ nwọn wipe, Idà ati ìyan kì yio
wá sori ilẹ yi ; nipa idà, pẹlu ìyan, ni
awọn woli wọnyi yio șegbe.
16 Ati awọn enia ti nwọn nsọ asọtẹlẹ
fun nì li a o lù bolẹ ni ita Jerusalemu,
nitori ìyan ati idà, nwọn kì yio ri ẹniti o
sin wọn, awọn aya wọn, ati ọmọkọnrin
wọn, ati ọmọbirin wọn : nitoriti emi o tu
ìwa-buburu wọn jade sori wọn.
17 Ki iwọ ki o si sọ ọ̀rọ yi fun wọn pe:
oju mi sun omije li oru ati li ọsan, kì yio
si dá, nitoriti a ti șa wundia ọmọbirin enia
mi li ọgbẹ nla kikoro gidigidi ni lilù na.
18 Bi emi ba jade lọ si papa, sa wò o, a
ri awọn ti a fi idà pa ! bi emi ba si wọ inu
ilu lọ, sa wò o, awọn ti npa ọ̀kara ikú
nitori iyan ! nitori awọn, ati awọn woli,
ati awọn alufa nwọ́ lọ si ilẹ ti nwọn kò mọ̀.
19 Iwọ ha ti kọ̀ Juda silẹ patapata?
ọkàn rẹ ti korira Sioni? ẽșe ti iwọ ti lù wa,
ti imularada kò si fun wa? awa nreti alafia,
kó si si rere, ati fun igba imularada, șu-
gbọn wò o, idãmu !
20 Awa jẹwọ iwa buburu wa, Oluwa, ati
aiședede awọn baba wa: nitori awa ti șẹ̀
si ọ.
21 Máșe korira wa, nitori orukọ rẹ,
máșe gan itẹ́ ogo rẹ, ranti, ki o máșe dà
majẹmu ti o ba wa dá.
22 Ẹniti o le mu ojo rọ̀ ha wà lọdọ awọn
orișa awọn keferi? tabi ọrun le rọ̀ òjo?
iwọ ha kọ́, Oluwa Ọlọrun wa? awa si nreti
rẹ: nitori iwọ li o da gbogbo nkan wọnyi.

## ORIN 15.

OLUWA si wi fun mi pe, Bi Mose ati
Samueli duro niwaju mi, sibẹ inu
mi kì yio si yipada si awọn enia yi: șá
wọn tì kuro niwaju mi, ki nwọn o si jade
lọ.
2 Yio si șe, nigbati nwọn ba wi fun ọ pe,
nibo ni awa o jade lọ? ki iwọ ki o sọ fun
wọn pe, Bayi li Oluwa wi ; awọn ti ikú, si
ikú, awọn ti idà, si idà ; ati awọn ti ìyan,
si ìyan, ati awọn ti igbèkun si igbèkun.
3 Emi si fi iru ijiya mẹrin sori wọn, li
Oluwa wi, idà lati pa, ajá lati wọ́ kiri,
ẹiyẹ oju-ọrun ati ẹranko ilẹ lati jẹ, ati lati
parun.
4 Emi o si fi wọn fun iwọsi ni gbogbo
ijọba aiye, nitori Manasse, ọmọ Hesekiah,
ọba Juda, nitori eyiti o ti șe ni Jerusalemu.
5 Nitori tani yio șãnu fun ọ, iwọ Jerusa-
lemu? tabi ti yio sọkun rẹ? tabi tani yio
wá lati bere alafia rẹ.
6 Iwọ ti kọ̀ mi silẹ, li Oluwa wi, iwọ ti
pada sẹhin ; nitorina emi o ná ọwọ mi si
ọ, emi o si pa ọ run ; ãrẹ̀ mu mi lati șe
iyọnu.
7 Emi o fi atẹ fẹ́ wọn si ẹnu-ọ̀na ilẹ na;
emi o pa awọn ọmọ wọn, emi o si pa enia
mi run, ẹniti kò yipada kuro ninu ọ̀na rẹ̀.
8 Awọn opo rẹ̀ o di pipọ ju iyanrin eti
okun: emi o mu arunni wa sori wọn, sori
iyá ati ọdọmọkọnrin li ọjọkanri; emi o mu
ifoya ati ìbẹrunla șubu lu wọn li ojiji.
9 Ẹniti o bi meje nsọ̀fọ o si jọwọ ẹmi rẹ̀
lọwọ ; õrùn rẹ̀ wọ̀ l'ọsan, oju ntì i, o si
ndamu : iyoku ninu wọn l'emi o si fifun
idà niwaju awọn ọta wọn, li Oluwa wi.
10 Egbe ni fun mi, iyá mi, ti o bi mi ni
ọkọnrin ija ati ijiyan gbogbo aiye! emi kò
win li elé, bẽni enia kò win mi li elé ; sibẹ
gbogbo wọn nfi mi ré.
11 Oluwa ni, Emi kì o tú ọ silẹ fun rere!
emi o mu ki ọta ki o bẹ̀ ọ ni ìgba ibi ati ni
ìgba ipọnju!
12 A ha le ṣẹ irin, irin ariwa, ati idẹ bi?
13 Ohun-ini ati ișura rẹ li emi o fi fun
ijẹ, li aigbowo, nitori gbogbo ẹ̀șẹ rẹ, ni
àgbegbe rẹ.
14 Emi o si mu ki awọn ọta rẹ kó wọn lọ
si ilẹ ti iwọ kò mọ̀ ; nitoriti iná njo ni
ibinu mi, ti yio jo lori rẹ.
15 Oluwa, iwọ mọ̀, ranti mi, bẹ̀ mi wò,
ki o si gbẹsan mi lara awọn oninunibini
mi! máșe mu mi kuro nitori ipamọra rẹ:
mọ̀ pe, mo ti jiya itiju nitori rẹ!
16 Nigbati a ri ọ̀rọ rẹ, emi si jẹ wọn,
ọ̀rọ rẹ si jẹ inu didùn mi, nitori orukọ rẹ
li a fi npè mi, iwọ Oluwa, Ọlọrun awọn
ọmọ-ogun!
17 Emi kò jõko ni ajọ awọn ẹlẹgan! ki

Digitized by Google

emi si ni ayọ̀ ; mo joko emi nikan, nitori
ọwọ rẹ : nitori iwọ ti fi ibanujẹ kún mi.
18 Ẽṣe ti irora mi pẹ titi, ati ọgbẹ mi jẹ
alaiwotan, ti o kọ̀ lati jina ? lõtọ iwọ si dabi
kanga ẹtan fun mi, bi omi ti kò duro ?
19 Nitorina, bayi li Oluwa wi, Bi iwọ ba
yipada, nigbana li emi o si tun mu ọ pada
wá, iwọ o si duro niwaju mi : bi iwọ ba si
yà eyi ti iṣe iyebiye kuro ninu buburu, iwọ
o dabi ẹnu mi : nwọn o si yipada si ọ ;
ṣugbọn iwọ máṣe yipada si wọn.
20 Emi o si ṣe ọ fun awọn enia yi bi odi
idẹ ati alagbara : nwọn o si ba ọ jà, ṣugbọn
nwọn kì yio le bori rẹ, nitori emi wà pẹlu
rẹ, lati gbà ọ là ati lati gbà ọ silẹ, li Oluwa
wi.
21 Emi o si gba ọ silẹ kuro lọwọ awọn
enia buburu, emi o si rà ọ pada kuro lọwọ
awọn ìka.

## ORI 16.

ỌRỌ Oluwa tọ̀ mi wá wipe :
2 Iwọ kò gbọdọ ni aya, bẽni iwọ kò
gbọdọ ni ọmọkọnrin tabi ọmọbirin ni
ihinyi.
3 Nitori bayi li Oluwa wi niti ọmọ-kọn-
rin ati ọmọbirin ti a bi ni ihinyi, ati niti
awọn iya wọn ti o bi wọn, ati niti awọn
baba wọn ti o bi wọn ni ilẹ yi.
4 Nwọn o kú ikú àrun : a kì yio ṣọ̀fọ
wọn ; bẽni a kì yio si sin wọn ; nwọn o si
di àtan lori ilẹ : a o fi idà ati ìyan run wọn,
ati okú wọn yio di onjẹ fun ẹiyẹ oju-ọrun,
ati fun ẹranko ilẹ.
5 Nitori bayi li Oluwa wi, máṣe wọ inu
ile ãwẹ̀, bẽni ki iwọ máṣe lọ ṣọ̀fọ, tabi lọ
pohùnrere ẹkun wọn ; nitori emi ti mu
alafia mi kuro lọdọ enia yi, li Oluwa wi,
ani ãnu ati iyọ́nu.
6 Ati ẹni-nla ati ẹni-kekere yio kú ni ilẹ
yi, a kì yio sin wọn, bẽni nwọn kì yio fá
ori wọn nitori wọn.
7 Bẽni ẹnikan kì yio bu àkara lati ṣọ̀fọ
fun wọn, lati tù wọn ninu nitori okú ; bẽni
ẹnikan kì yio fun wọn ni ago itunu mu ni-
tori baba wọn, tabi nitori iya wọn.
8 Iwọ kò gbọdọ lọ sinu ile àse, lati joko
pẹlu wọn lati jẹ ati lati mu.
9 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun,
Ọlọrun Israeli, wi ; Sa wò o, emi o mu
ohùn inudidùn, ati ohùn ayọ̀, ohùn ọkọ-
iyawo, ati ohùn iyawo dakẹ ni ihinyi loju
nyin ati li ọjọ nyin.
10 Yio si ṣe, nigbati iwọ o ba fi gbogbo
ọ̀rọ wọnyi han enia yi, ti nwọn o wi fun ọ
pe, Ẽṣe ti Oluwa fi sọ̀rọ gbogbo ohun
buburu nla yi si wa, tabi kini aiṣedede wa?
tabi ẹ̀ṣẹ kini awa da si Oluwa Ọlọrun wa?
11 Nigbana ni iwọ o wi fun wọn pe,
Nitoripe awọn baba nyin ti kọ̀ mi silẹ, li
Oluwa wi, ti nwọn si rìn tọ̀ ọlọrun miran
lọ, ti nwọn si sìn wọn, ti nwọn si foribalẹ
fun wọn, ti nwọn kọ̀ mi silẹ, ti nwọn kò
pa ofin mi mọ ;
12 Ati pẹlu pe, ẹnyin ti ṣe buburu jù
awọn baba nyin lọ : nitorina sa wò o,
ẹnyin rìn olukuluku nyin, ni agidi ọkàn
buburu rẹ̀, ki ẹnyin ki o má ba gbọ́ temi :
13 Emi o si ta nyin nu kuro ni ilẹ yi,
sinu ilẹ ti ẹnyin kò mọ̀, ẹnyin tabi awọn
baba nyin, nibẹ li ẹnyin o sin ọlọrun
miran, lọsan ati loru nibiti emi kì yio ṣe
oju-rere fun nyin.
14 Nitorina, sa wò o, Bayi li Oluwa wi,
ọjọ mbọ̀, ti a kì o wi mọ́ pe, Oluwa mbẹ ti
o mu awọn ọmọ Israeli jade kuro ni ilẹ
Egipti ;
15 Ṣugbọn, Oluwa mbẹ ti o mu awọn
ọmọ Israeli jade wá kuro ni ilẹ ariwa, ati
kuro ni ilẹ nibiti o ti lé wọn si : emi o si
tun mu wọn wá si ilẹ wọn, eyiti mo fi fun
awọn baba wọn.
16 Sa wò o, emi o ran apẹja pupọ, li
Oluwa wi, nwọn o si dẹ wọn : lẹhin eyini,
emi o rán ọdẹ pupọ, nwọn o si dẹ wọn lati
ori oke-nla gbogbo, ati ori oke kekere gbo-
gbo, ati lati inu palapala okuta jade.
17 Nitoriti oju mi mbẹ lara ọ̀na wọn
gbogbo : nwọn kò pamọ kuro niwaju mi,
bẽni ẹ̀ṣẹ wọn kò farasin kuro li oju mi.
18 Li atetekọṣe, emi o san ẹsan ìwa-bu-
buru mejeji wọn, ani, ẹ̀ṣẹ wọn nitoriti
nwọn ti bà ilẹ mi jẹ, nwọn ti fi okú ati
ohun ẹgbin ati irira wọn kún ilẹ ini mi.
19 Oluwa, agbara mi ati ilu-odi mi ! àbo
mi li ọjọ ipọnju ! awọn orilẹ-ède yio tọ̀ ọ
wá, lati ipẹkun aiye, nwọn o si wipe, Lõtọ,
awọn baba wa ti jogun eke, ohun asan,
iranlọwọ kò si si ninu wọn !
20 Enia lè ma dá ọlọrun fun ara rẹ̀ :
nitori awọn wọnyi kì iṣe ọlọrun ?
21 Nitorina, sa wò o, emi o mu ki nwọn
ki o mọ̀, lẽkan yi, emi o si mu ki nwọn ki
o mọ̀ ọwọ mi ati ipa mi ; nwọn o si mọ̀ pe,
orukọ mi ni JEHOFA.

## ORI 17.

ẸṢẸ Juda ni a fi kalamu irin kọ, a fi
ṣonṣo okuta adamante gbẹ ẹ sori walã
aiya wọn, ati sori iwo pẹpẹ nyin.
2 Bi awọn ọmọ wọn ba ranti pẹpẹ wọn

Digitized by Google

ati ere òrișa wọn, lẹba igi tutu, ati ibi giga
wọnni.
3 Oke mi ti o wà ni papa! emi o fi ohun-
ini rẹ pẹlu ọrọ̀ rẹ gbogbo fun ijẹ, ati ibi
giga rẹ, nitori ẹ̀ṣẹ yi gbogbo àgbegbe rẹ ka.
4 Iwọ fun ara rẹ ni yio jọ̃ ogún rẹ lọwọ,
ti mo ti fi fun ọ, emi o mu ọ sin awọn ọta
rẹ ni ilẹ ti iwọ kò mọ̀ ri: nitoriti ẹnyin ti
tinabọ ibinu mi, ti yio jo lailai.
5 Bayi li Oluwa wi: Egbe ni fun ẹniti
o gbẹkẹle enia, ti o fi ẹlẹran ara ṣe apá rẹ̀,
ẹniti ọkàn rẹ̀ si ṣi kuro lọdọ Oluwa!
6 Nitoripe yio dabi alaini ni aginju, ti
kò si ri pe rere mbọ̀: ṣugbọn yio gbe ibi
iyangbẹ ilẹ wọnni ni aginju, ilẹ iyọ̀ ti a kì
igbe inu rẹ̀.
7 Ibukun ni fun ẹniti o gbẹkẹle Oluwa,
ti o si fi Oluwa ṣe igbẹkẹle rẹ̀!
8 Yio si dabi igi ti a gbìn lẹba omi, ti o
nà gbòngbo rẹ̀ lẹba odò, ti kì yio bẹ̀ru bi
õru ba de, ṣugbọn ewe rẹ̀ yio tutu, kì yio
si ni ijaya ni ọdun ọ̀dá, bẽni kì yio dẹkun
lati ma so eso.
9 Ọkàn enia kún fun ẹ̀tan jù ohun gbo-
gbo lọ, o si buru jayi! tani o le mọ̀ ọ?
10 Emi, Oluwa, ni iwá awari ọkàn enia,
emi ni ndan inu wò, ani lati fi fun oluku-
luku gẹgẹ bi ọ̀na rẹ̀, ati gẹgẹ bi eso iṣe rẹ̀.
11 Bi aparo ti isaba lori ẹyin ti kò yin,
bẹ̃ gẹgẹ ni ẹniti o kó ọrọ̀ jọ, ṣugbọn kì iṣe
ni ododo; yio fi i silẹ lagbedemeji ọjọ rẹ̀,
ati ni opin rẹ̀ yio jẹ aṣiwere.
12 Itẹ́ ogo! ibi giga lati ipilẹṣẹ ni ibi ile
mimọ́ wa!
13 Oluwa ni ireti Israeli! gbogbo awọn
ti o kọ̀ ọ silẹ yio dãmu, awọn ti o yẹ̀ kuro
lọdọ mi, ni a o kọ orukọ wọn sinu ẽkuru,
si ori ilẹ, nitori nwọn ti kọ̀ Oluwa silẹ,
orisun omi iye.
14 Wò mi sàn, Oluwa, emi o si sàn!
gbà mi là, emi o si là, nitori iwọ ni iyìn
mi!
15 Sa wò o, nwọn wi fun mi pe, Nibo ni
ọ̀rọ Oluwa wà? jẹ ki o wá wayi.
16 Bi o ṣe ti emi ni, emi kò yara kuro
ki emi má ṣe oluṣọ-agutan, lẹhin rẹ, bẽni
emi kò bere ọjọ ipọnju, iwọ mọ̀: eyiti o
jade li ète mi, o ti hàn niwaju rẹ.
17 Máṣe di ibẹ̀ru fun mi! iwọ ni ireti
mi li ọjọ ibi!
18 Jẹ ki oju ki o tì awọn ti o nṣe inuni-
bini si mi, ṣugbọn má jẹ ki oju ki o tì mi:
jẹ ki nwọn ki o dãmu, ṣugbọn máṣe jẹ ki
emi ki o dãmu: mu ọjọ ibi wá sori wọn,
ki o si fi iparun iṣẹpo meji pa wọn run.
19 Bayi li Oluwa wi fun mi; Lọ, ki o
si duro ni ẹnu-ọ̀na awọn enia nibi ti awọn
ọba Juda nwọle, ti nwọn si njade, ati ni
gbogbo ẹnu-bode Jerusalemu.
20 Ki o si wi fun wọn pe, Ẹ gbọ́ ọ̀rọ
Oluwa, ẹnyin ọba Juda ati gbogbo Juda,
ati gbogbo ẹnyin olugbe Jerusalemu, ti o
nkọja ninu ẹnu-bode wọnyi.
21 Bayi li Oluwa wi, Ẹ kiyesi li ọkàn
nyin, ki ẹ máṣe ru ẹrù li ọjọ isimi, bẽni ki
ẹ má si ṣe mu u wá ninu ẹnu-bode Jerusa-
lemu:
22 Bẽni ki ẹ má si ṣe gbe ẹrù jade kuro
ninu ile nyin li ọjọ isimi, bẽni ki ẹ má ṣe
iṣẹkiṣẹ, ṣugbọn ki ẹ yà ọjọ isimi si mimọ́,
gẹgẹ bi mo ti paṣẹ fun awọn baba nyin.
23 Ṣugbọn nwọn kò gbọ́, nwọn kò si tẹti
silẹ, nwọn mu ọrun wọn le, ki nwọn ki o
má ba gbọ́, ati ki nwọn ki o má gbà ẹkọ.
24 Yio si ṣe bi ẹnyin ba tẹtisilẹ gidigidi
si mi, li Oluwa wi, ti ẹ kò ba ru ẹrù kọja
ni ẹnu-bode ilu yi li ọjọ isimi, ti ẹ ba si yà
ọjọ isimi si mimọ, ti ẹ kò si ṣe iṣẹkiṣẹ ninu
rẹ̀.
25 Nigbana ni nwọn o wọ ẹnu-bode ilu
yi, ani ọba, ati ijoye ti o joko lori itẹ
Dafidi, awọn ti ngun kẹkẹ ati ẹṣin, awọn
wọnyi pẹlu ijoye wọn, awọn ọkọnrin Juda,
ati olugbe Jerusalemu: nwọn o si ma gbe
ilu yi lailai.
26 Nwọn o si wá lati ilu Juda wọnni,
ati lati àgbegbe Jerusalemu yikakiri, ati
lati ilẹ Benjamini, lati pẹtẹlẹ, ati lati oke,
ati lati gusu wá, nwọn o si mu ọrẹ-ẹbọ
sisun, ati ọrẹ ẹran ati turari, ati awọn
wọnyi ti o mu iyìn wá si ile Oluwa.
27 Ṣugbọn bi ẹnyin kò ba gbọ́ ti emi,
lati ya ọjọ isimi si mimọ́, ti ẹ kò si ru ẹrù,
ti ẹ kò tilẹ wọ ẹnu-bode Jerusalemu li ọjọ
isimi; nigbana ni emi o da iná ni ẹnu-bode
wọnni, yio si jo ãfin Jerusalemu run, a kì
o si pa a.

## ORI 18.

Ọ̀RỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa
wipe,
2 Dide, sọkalẹ lọ si ile amọkoko, nibẹ li
emi o mu ọ gbọ́ ọ̀rọ mi.
3 Mo si sọkalẹ lọ si ile amọkoko, sa wò
o, o mọ iṣẹ kan lori kẹkẹ.
4 Ati ohun-èlo, ti o fi amọ mọ, si bajẹ
lọwọ amọkoko na: nigbana ni o si mọ
ohun-elo miran, bi o ti ri li oju amọkoko
lati mọ ọ.
5 Ọrọ Oluwa si tọ̀ mi wá wipe,
6 Ẹnyin ile Israeli, emi kò ha le fi nyin
ṣe gẹgẹ bi amọkoko yi ti ṣe, li Oluwa wi:

Digitized by Google

sa wò o, gẹgẹ bi amọ̀ li ọwọ amọkoko, bẹ̃ni
ẹnyin wà li ọwọ mi, ile Israeli.
7 Lojukanna ti emi sọ̀rọ si orilẹ-ède kan
ati si ijọba kan lati fà a tu, ati lati fà a
lulẹ, ati lati pa a run.
8 Bi orilẹ-ède na ti mo ti sọ ọ̀rọ si ba
yipada kuro ninu ìwa-buburu rẹ̀, emi o yi
ọkàn mi pada niti ibi ti emi ti rò lati ṣe si
wọn.
9 Ati lojukanna ti emi sọ ọ̀rọ si orilẹ-ède
kan ati si ijọba kan, lati tẹ̀ ẹ do ati lati
gbìn i.
10 Bi o ba ṣe ibi niwaju mi, ti kò si gbà
ohùn mi gbọ́: nigbana ni emi o yi ọkàn mi
pada niti rere, eyiti mo wi pe, emi o ṣe fun
wọn.
11 Njẹ nisisiyi, sa sọ fun awọn enia
Juda, ati fun awọn olugbe Jerusalemu
wipe, Bayi li Oluwa wi, sa wò o, emi npete
ibi si nyin, emi si nṣe ipinnu kan si nyin,
si yipada, olukuluku kuro ninu ọ̀na buburu
rẹ̀, ki ẹ si tun ọ̀na ati iṣe nyin ṣe rere.
12 Nwọn si wipe: Lasan ni: nitori awa
o rìn nipa ipinnu wa, olukuluku yio si
huwa agidi ọkàn buburu rẹ̀.
13 Nitorina bayi li Oluwa wí, Ẹ sa bère
ninu awọn orilẹ-ède, tani gbọ́ iru ohun
wọnni: wundia Israeli ti ṣe ohun kan ti o
buru jayi.
14 Omi ojo-didì Lebanoni yio ha dá lati
ma ṣàn lati apata oko? tabi odò ti o jina,
ti o tutu, ti o nṣan, yio ha gbẹ bi?
15 Nitoripe awọn enia mi gbàgbe mi,
nwọn ti sun turari fun ohun asan, nwọn si
ti mu ki nwọn ki o ṣubu loju ọ̀na wọn, ni
ipa igbã̀ni; lati rìn ni ipa ti a kò tẹ̀.
16 Lati sọ ilẹ wọn di ahoro, ati ẹ̀gan lai-
lai; olukuluku ẹniti o ba kọja nibẹ, yio
dã̀mu yio mì ori rẹ̀ si i.
17 Emi o tú wọn ka gẹgẹ bi ẹ̀fufu ila-
õrùn niwaju ọta wọn; emi o kọ ẹ̀hin mi si
wọn, kì yio ṣe oju mi, ni ọjọ iparun wọn.
18 Nigbana ni nwọn wipe, Wá, ẹ jẹ ki
a pinnu ìwa ibi si Jeremiah, nitori ofin kì
yio ṣegbe lọwọ alufa, tabi igbimọ lọwọ
ọlọgbọ́n, tabi ọ̀rọ lọwọ woli: ẹ wá, ẹ jẹ ki
a fi ahọn wa lù u, ki a má si kiyesi ohun
kan ninu ọ̀rọ rẹ̀.
19 Kiyesi mi, Oluwa, ki o si gbọ́ ohùn
awọn ti nni mi lara.
20 A ha le fi ibi san rere? nitori nwọn
ti wà iho fun ẹmi mi. Ranti pe emi ti
duro niwaju rẹ lati sọ ohun rere nipa ti
wọn, ati lati yi ibinu rẹ kuro lọdọ wọn.
21 Nitorina, fi awọn ọmọ wọn fun ìyan,
ki o si fi idà pa wọn, jẹ ki aya wọn ki o di
alailọmọ ati opó: ki a si fi ìka pa awọn
ọkọnrin wọn, jẹ ki a fi idà pa awọn ọdọ-
mọde wọn li ogun.
22 Jẹ ki a gbọ́ igbe lati ilẹ wọn, nigbati
iwọ o mu ẹgbẹ kan wá lojiji sori wọn: ni-
tori nwọn ti wà ihò lati mu mi, nwọn si
dẹ okùn fun ẹsẹ mi.
23 Ṣugbọn nisisiyi, Oluwa, iwọ mọ̀ gbo-
gbo igbimọ wọn si mi lati pa mi, máṣe bò
ẹbi wọn mọlẹ, bẹ̃ni ki iwọ máṣe pa ẹṣẹ wọn
rẹ́ kuro niwaju rẹ, jẹ ki nwọn ki o ṣubu
niwaju rẹ, bẹ̃ni ki iwọ ki o ṣe si wọn ni ọjọ
ibinu rẹ.

## ORI 19.

BAYI li Oluwa wi, Lọ, rà igo amọ ti amọ-
koko, si mu ninu awọn àgba enia, ati
awọn àgba alufa;
2 Ki o si lọ si afonifoji ọmọ Hinnomu ti
o wà niwaju ẹnu-bode Harsiti, nibẹ ni ki o
si kede gbogbo ọ̀rọ ti emi o sọ fun ọ.
3 Ki o si wipe, Ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, ẹnyin
ọba Juda, ati olugbe Jerusalemu; Bayi li
Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi:
sa wò o, emi o mu ibi wá sihin yi, eyiti eti
gbogbo awọn ti o ba gbọ́ ọ, yio ho.
4 Nitori nwọn ti kọ̀ mi silẹ, nwọn ti sọ
ihín yi di iyapa, nwọn si ti sun turari ninu
rẹ̀ fun awọn ọlọrun miran, eyiti awọn, tabi
awọn baba wọn kò mọ̀ ri, tabi awọn ọba
Juda, nwọn si ti fi ẹ̀jẹ alaiṣẹ kún ibi yi;
5 Nwọn ti kọ́ ibi giga fun Baali pẹlu,
lati fi iná sun ọmọkọnrin wọn, bi ẹbọ-ọrẹ
sisun fun Baali, eyiti emi kò pa laṣẹ lati
ṣe, ti emi kò si sọ, tabi ti kò si ru soke
ninu mi:
6 Nitorina, sa wò o, ọjọ mbọ̀, li Oluwa
wi, a kì yio pe orukọ ibi yi ni Tofeti mọ,
tabi afonifoji ọmọ Hinnomu, ṣugbọn Afoni-
foji ipakupa.
7 Emi o sọ igbimọ Juda ati Jerusalemu
di asan ni ibi yi; emi o mu ki nwọn ki o
ṣubu niwaju ọta wọn, ati lọwọ awọn ti o
nwá ẹmi wọn, okú wọn ni a o fi fun ẹiyẹ
oju-ọrun, ati ẹranko ilẹ fun onjẹ.
8 Emi o si sọ ilu yi di ahoro, ati ẹ̀gan,
ẹnikẹni ti o ba nkọja lọ nibẹ yio dã̀mu, yio
si poṣe nitori gbogbo ìna rẹ̀.
9 Emi o si mu ki nwọn ki o jẹ ẹran-ara
awọn ọmọkọnrin wọn, ati ẹran-ara awọn
ọmọbirin wọn, ati ẹnikini wọn yio jẹ ẹran-
ara ẹnikẹji ni igba idoti ati ihamọ, ti awọn
ọta wọn, ati awọn ti o nwá ẹmi wọn yio ha
wọn mọ.
10 Nigbana ni iwọ o fọ igo na li oju
awọn ti o ba ọ lọ.

Digitized by Google

11 Ki o si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi: Bẽ gẹgẹ li emi o fọ enia yi ati ilu yi, bi a ti ifọ ohun-èlo amọkoko, ti ẹnikan kò le tun ṣe mọ, nwọn o si sin wọn ni Tofeti, nitoriti aye kò si lati sinkú.
12 Bayi li emi o ṣe si ibi yi, li Oluwa wi, ati si olugbe inu rẹ̀, emi o tilẹ ṣe ilu yi bi Tofeti:
13 Gbogbo ile Jerusalemu ati ile awọn ọba Juda ni a o sọ di alaimọ́ bi Tofeti, gbogbo ile wọnni, lori orule eyiti a ti sun turari fun ogun ọrun, ti a si ru ẹbọ mimu fun ọlọrun miran.
14 Nigbana ni Jeremiah wá si Tofeti, nibiti Oluwa ti rán a lati sọ asọtẹlẹ; o si duro ni àgbala ile Oluwa; o si wi fun gbogbo awọn enia pe,
15 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi; Sa wò o, emi o mu wá sori ilu yi, ati sori ileto rẹ̀ gbogbo ibi ti mo ti sọ si i, nitori ti nwọn ti wà ọrun kì, ki nwọn ki o má bà gbọ́ ọ̀rọ mi.

## ORI 20.

NJẸ Paṣuri, ọmọ Immeri, alufa, ti iṣe olori olutọju ni ile Oluwa, gbọ́ pe, Jeremiah sọ asọtẹlẹ ohun wọnyi.
2 Nigbana ni Paṣuri lù Jeremiah, woli, o si kàn a li àba ti o wà ni ẹnu-ọ̀na Benjamini, ti o wà li òke ti o wà lẹba ile Oluwa.
3 O si ṣe ni ọjọ keji, Paṣuri mu Jeremiah kuro ninu àba. Nigbana ni Jeremiah wi fun u pe, Oluwa kò pe orukọ rẹ ni Paṣuri (ire-yika-kiri), bikoṣe Magori-missabibu (idãmu-yika-kiri.)
4 Nitori bayi li Oluwa wi, sa wò o, emi o fi ọ le idãmu lọwọ, pẹlu gbogbo awọn ọrẹ rẹ, nwọn o ṣubu nipa idà awọn ọta wọn, oju rẹ yio si ri i, emi o si fi gbogbo Juda le ọwọ ọba Babeli, on o si mu wọn lọ ni igbèkun si Babeli, yio si fi idà pa wọn.
5 Pẹlupẹlu emi o fi ọrọ̀ ilu yi, pẹlu ère rẹ̀ ati ohun iyebiye rẹ̀, ati gbogbo iṣura awọn ọba Juda li emi o fi le ọwọ awọn ọta wọn, ti yio jẹ wọn, ti yio si mu wọn lọ si Babeli.
6 Ati iwọ, Paṣuri, ati gbogbo awọn ti o ngbe inu ile rẹ ni yio lọ si igbekun, iwọ o wá si Babeli, ati nibẹ ni iwọ o kú si, a o si sin ọ sibẹ, iwọ, ati gbogbo ọrẹ rẹ ti iwọ ti sọ asọtẹlẹ eke fun.
7 Oluwa, iwọ ti fi ọ̀rọ rọ̀ mi, emi si gba rirọ̀! iwọ li agbara jù mi lọ, o si bori mi; emi di ẹni iyọ-ṣuti-si lojojumọ, gbogbo wọn ni ngàn mi!
8 Nitori lati igba ti mo ti sọ̀rọ, emi kigbe, mo ke, Iwa-agbara, ati iparun, nitori a sọ ọ̀rọ Oluwa di ohun ẹ̀gan ati itiju fun mi lojojumọ.
9 Nitorina mo si wipe, emi kì yio mu ni ranti rẹ̀, emi kì yio si sọ ọ̀rọ li orukọ rẹ̀ mọ́. Ṣugbọn ọ̀rọ rẹ̀ mbẹ bi iná ti njó ninu mi ti a se mọ inu egungun mi, o si rẹ̀ mi lati pa a mọra, emi kò le ṣe e.
10 Nitoriti mo gbọ́ ẹgan ọ̀pọlọpọ, idãmu niha gbogbo, nwọn wipe: fi sùn, awa o si fi sùn. Gbogbo awọn ọrẹ mi, ati gbogbo awọn ẹgbẹ mi wipe: bọya a o tãn jẹ, awa o si ṣẹgun rẹ̀, a o si gbẹsan wa lara rẹ̀.
11 Ṣugbọn Oluwa mbẹ lọdọ mi bi akọni ẹlẹrù, nitorina awọn ti nṣe inu-nibini si mi yio ṣubu, nwọn kì yio le bori: oju yio tì wọn gidigidi, nitoripe nwọn kì o ṣe rere, itiju lailai, ti a kì o gbagbe!
12 Oluwa awọn ọmọ-ogun, iwọ ti ndán olododo wò, iwọ si ri inu ati ọkàn, emi o ri ẹsan rẹ lara wọn: nitoriti mo ti fi ọ̀ran mi le ọ lọwọ!
13 Ẹ kọrin si Oluwa, ẹ yìn Oluwa, nitoriti o ti gbà ọkàn talaka kuro lọwọ awọn oluṣe buburu.
14 Ègbe ni fun ọjọ na ti a bi mi! ọjọ na ti iya mi bi mi, ki o má ri ibukun!
15 Egbe ni fun ọkọnrin na ti o mu ihìn tọ̀ baba mi wá, wipe, Ọmọkọnrin li a bi fun ọ; o mu u yọ̀.
16 Ki ọkọnrin na ki o si dabi ilu wọnni ti Oluwa ti bì ṣubu, li aiyi ọkàn pada, ki o si gbọ́ ẹkun li owurọ, ati ọ̀fọ li ọsangangan.
17 Nitoriti kò pa mi ni inu iya mi, tobẽ ki iya mi di isà mi, ki o loyun mi lailai.
18 Ẽṣe ti emi fi jade kuro ninu iya mi, lati ri irora ati oṣi, ati lati pari ọjọ mi ni itiju!

## ORI 21.

ỌRỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa nigbati Sedekiah, ọba, ran Paṣuru, ọmọ Melkiah, ati Sefaniah, ọmọ Maaseah, alufa, wipe,
2 Bère, emi bẹ ọ, lọdọ Oluwa fun wa; nitori Nebukadnessari, ọba Babeli, ṣi ogun tì wa; bọya bi Oluwa yio ba wa lò gẹgẹ bi gbogbo iṣẹ iyanu rẹ̀, ki on ki o le lọ kuro lọdọ wa.
3 Nigbana ni Jeremiah wi fun wọn pe, Bayi li ẹnyin o wi fun Sedekiah.
4 Bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi: wõ, emi o yi ihamọra ogun ti o wà ni ọwọ nyin pada, eyiti ẹnyin nfi ba ọba Babeli, ati

Digitized by Google

awọn ara Kaldea jà, ti o doti nyin lẹhin odi, emi o kó wọn jọ si ãrin ilu yi.

5 Emi tikarami yio fi ọwọ ninà ati apa lile ba nyin jà, pẹlupẹlu ni ibinu, ati ni ikannu pẹlu ibinu nla.

6 Emi o si pa awọn olugbe ilu yi, enia pẹlu ẹranko, nwọn o ti ipa àjakalẹ-arun nlanla kú.

7 Lẹhin eyi, li Oluwa wi, emi o fi Sedekiah, ọba Juda, ati awọn iranṣẹ rẹ̀, ati awọn enia, ati awọn ti o kù ni ilu yi lọwọ ajakalẹ-àrun ati lọwọ idà, ati lọwọ ìyan; emi o fi wọn le Nebukadnessari, ọba Babeli lọwọ, ati le ọwọ awọn ọta wọn, ati le ọwọ awọn ti nwá ẹmi wọn: yio si fi oju idà pa wọn; kì yio da wọn si, bẹ̃ni kì yio ni iyọ́nu tabi ãnu.

8 Ati fun enia yi ni ki iwọ ki o wipe, Bayi li Oluwa wi; Sa wò o, emi fi ọ̀na iye ati ọ̀na ikú lelẹ niwaju nyin.

9 Ẹniti o ba joko ninu ilu yi, yio ti ipa idà kú, ati nipa ìyan ati nipa àjakalẹ-àrun: ṣugbọn ẹniti o ba jade ti o si ṣubu si ọwọ awọn ara Kaldea ti o dó tì nyin, yio yè, ẹmi rẹ̀ yio si dabi ijẹ fun u.

10 Nitori emi ti yi oju mi si ilu yi fun ibi, kì isi iṣe fun rere, li Oluwa wi: a o fi i le ọba Babeli lọwọ, yio fi iná kun u.

11 Ati fun ile ọba Juda; Ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa:

12 Ile Dafidi, Bayi li Oluwa wi, Mu idajọ ṣẹ-li owurọ, ki o si gba ẹniti a lọ lọwọ gba kuro li ọwọ aninilara, ki ibinu mi ki o má ba jade bi iná, ki o má si jo ti kì o si ẹniti yio pa a, nitori buburu iṣe nyin.

13 Wò o, Emi doju kọ nyin, olugbe afonifoji, ati ti okuta pẹtẹlẹ, li Oluwa wi, ẹnyin ti o wipe, Tani yio kọlu wa? ati tani yio wọ̀ inu ibugbe wa?

14 Ṣugbọn emi o jẹ nyin niya gẹgẹ bi eso iṣe nyin, li Oluwa wi; emi o si da iná ninu igbo rẹ ki o le jo gbogbo agbegbe rẹ.

## ORI 22.

BAYI li Oluwa wi, Sọkalẹ lọ si ile ọba Juda, ki o si sọ ọ̀rọ yi nibẹ.

2 Si wipe, Gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, ọba Juda, ti o joko ni itẹ Dafidi, iwọ, ati awọn iranṣẹ rẹ, ati awọn enia rẹ ti o wọle ẹnu-bode wọnyi.

3 Bayi li Oluwa wi; Mu idajọ ati ododo ṣẹ, ki o si gbà ẹniti a lọ lọwọ gbà kuro lọwọ aninilara, ki o máṣe fi agbara àti ìka lò alejo, alainibaba ati opó, bẹ̃ni ki o máṣe ta ẹ̀jẹ alaiṣẹ silẹ nihinyi.

4 Nitori bi ẹnyin ba ṣe ukan yi nitõtọ, nigbana ni awọn ọba yio wọle ẹnu-bode ilu yi, ti nwọn o joko lori itẹ Dafidi, ti yio gun kẹ̀kẹ ati ẹṣin, on, ati awọn iranṣẹ rẹ̀, ati enia rẹ̀.

5 Ṣugbọn bi ẹnyin kì yio ba gbọ́ ọ̀rọ wọnyi, Emi fi emitikarami bura, li Oluwa wi, pe, ile yi yio di ahoro.

6 Nitori bayi li Oluwa wi fun ile ọba Juda; Gileadi ni iwọ si mi, ori Lebanoni: sibẹ, lõtọ emi o sọ ọ di aginju, ati ilu ti a kò gbe inu wọn.

7 Emi o ya awọn apanirun sọtọ fun ọ, olukuluku pẹlu ihamọra rẹ̀: nwọn o si ke aṣayan igi kedari rẹ lulẹ, nwọn o si sọ wọn sinu iná.

8 Ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède yio rekọja lẹba ilu yi, nwọn o wi, ẹnikan fun ẹnikeji rẹ̀ pe, Ẽṣe ti Oluwa ṣe bayi si ilu nla yi?

9 Nigbana ni nwọn o dahùn pe, nitoriti nwọn ti kọ̀ majẹmu Oluwa Ọlọrun wọn silẹ; ti nwọn fi ori balẹ fun ọlọrun miran, nwọn si sìn wọn.

10 Ẹ máṣe sọkun fun okú, bẹ̃ni ki ẹ máṣe pohùnrere rẹ̀, ṣugbọn ẹ sọkun ẹ̀dun fun ẹniti o nlọ, nitori kì yio pada wá mọ, kì yio si ri ilẹ rẹ̀ mọ.

11 Nitori bayi li Oluwa wi fun Ṣallumu, ọmọ Josiah, ọba Juda, ti o jọba ni ipo Josiah, baba rẹ̀, ti o jade kuro nihin pe, On kì yio pada wá mọ.

12 Ṣugbọn yio kú ni ibi ti a mu u ni igbèkun lọ, kì yio si ri ilẹ yi mọ.

13 Egbe ni fun ẹniti o kọ́ ile rẹ̀, ti kì iṣe nipa ododo, ati iyẹwu rẹ̀, ti kì iṣe nipa ẹ̀tọ́: ti o lò iṣẹ ọwọ aladugbo rẹ̀ lọfẹ, ti kò fi ere iṣẹ rẹ̀ fun u.

14 Ti o wipe, emi o kọ ile ti o ni ibò fun ara mi, ati iyẹwu nla, ti o ke oju ferese fun ara rẹ̀, ti o fi igi kedari bò o, ti o si fi ajẹ̀ kùn u.

15 Iwọ o ha jọba, nitori iwọ fi igi kedari dije? baba rẹ kò ha jẹ, kò ha mu? o si ṣe idajọ ati ododo, nitorina o dara fun u.

16 O dajọ ọ̀ran talaka ati alaini; o dara fun u: bi ãti mọ̀ mi kọ́ eyi? li Oluwa wi.

17 Ṣugbọn oju rẹ ati ọkàn rẹ kì iṣe fun ohunkohun bikoṣe ojukokoro rẹ, ati lati ta ẹ̀jẹ alaiṣẹ silẹ, ati lati ṣe ininilara ati agbara.

18 Nitorina bayi li Oluwa wi nitori Jehoiakimu ọmọ Josiah, ọba Juda, nwọn kì yio ṣọ̀fọ fun u, wipe, Oṣe! arakọnrin mi! tabi Oṣe! arabirin mi! nwọn kì o ṣọ̀fọ fun u pe, Oṣe, oluwa! tabi Oṣe, ọlọla!

19 A o ṣin i ni isinkú kẹtẹkẹtẹ, ti a wọ́ ti a si sọ junù kuro ni ẹnu-bode Jerusalemu

Digitized by Google

20 Goke lọ si Lebanoni, ki o si ke, ki o
si gbe ohùn rẹ soke ni Başani, ki o kigbe
lati Abarimu, nitori a ti şé gbogbo olufẹ rẹ
tutu,
21 Emi ti ba ọ sộrọ ni ìgba ire rẹ; iwọ
wipe, emi kì yio gbộ. Eyi ni ìwa rẹ lati
igba ewe rẹ wá, ti iwọ kò si gba ohùn mi
gbọ.
22 Ẹfũfu yio fẹ gbogbo oluşọ-agutan rẹ
lọ, ati awọn olufẹ rẹ yio lọ si ìgbekun: ni-
tõtọ, ni wakati na ni oju yio tì ọ, iwọ o si
dãmu nitori gbogbo buburu rẹ.
23 Iwọ, olugbe Lebanoni, ti o tẹ́ itẹ si
ori igi kedari, iwọ o ti jẹ otoşi to, nigbati
irora ba deba ọ, irora bi obirin ti nrọbi!
24 Bi emi ti wà, li Oluwa wi, bi Koniah,
ọmọ Jehoiakimu, ọba Juda, tilẹ jẹ oruka-
èdidi lọwọ ọtun mi, sibẹ emi o fà ọ tu kuro
nibẹ.
25 Emi o si fi ọ le ọwọ awọn ti o nwá
ẹmi rẹ, ati le ọwọ ẹniti iwọ bẹ̀ru rẹ̀, ani le
ọwọ Nebukadnessari, ọba Babeli, ati ọwọ
awọn ara Kaldea.
26 Emi o tì ọ sode, ati iya rẹ ti o bi ọ si
ilẹ miran, nibiti a kò bi nyin si; nibẹ li
ẹnyin o si kú.
27 Şugbọn ilẹ na ti ẹnyin fẹ li ọkàn
nyin lati pada si, nibẹ ni ẹnyin kì o pada
si mọ.
28 Ọkọnrin yi, Koniah, ohun-èlo ẹlẹgan
fifọ ha ni bi? o ha dabi ohun-èlo ti kò ni
ẹwà lara? èşe ti a tì wọn jade, on, ati iru-
ọmọ rẹ̀, ti a si le wọn jade si ilẹ ti nwọn kò
mọ̀?
29 Ilẹ! ilẹ! ilẹ! gbộ ọ̀rọ Oluwa!
30 Bayi li Oluwa wi, Ẹ kọwe pe, ọkọnrin
yi alailọmọ ni, ẹniti kì yio ri rere li ọjọ
aiye rẹ̀: nitori ọkan ninu iru-ọmọ rẹ̀ kì yio
ri rere, ti yio fi joko lori itẹ Dafidi, ti yio
si fi tun jọba lori Juda.

## ORI 23.

EGBE ni fun awọn oluşọ-agutan, ti nmu
agbo-ẹran mi şìna, ti o si ntú wọn ka,
li Oluwa wi.
2 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli
wi si oluşọ-agutan wọnni, ti nṣọ enia mi;
Ẹnyin tú agbo-ẹran mi ká, ẹ le wọn junù,
ẹnyin kò si bẹ̀ wọn wò, sa wò o, emi o bẹ̀
nyin wò nitori buburu işe nyin, li Oluwa
wi.
3 Emi o si kó iyokù agbo-ẹran mi jọ
lati inu gbogbo ilẹ, ti mo ti le wọn si, emi
o si mu wọn pada wá sinu pápá oko wọn,
nwọn o bi si i, nwọn o si rẹ̀ si i.
4 Emi o gbe oluşọ-agutan dide fun wọn,
ti yio bộ wọn: nwọn kì yio bẹ̀ru mọ́, tabi
nwọn kì yio si dãmu, bẹ̃li ọkan ninu wọn
kì yio si sọnu, li Oluwa wi.
5 Sa wò o, ọjọ mbọ, li Oluwa wi, ti emi
o gbe Ẹka ododo soke fun Dafidi, yio si jẹ
Ọba, yio si şe rere, yio si şe idajọ ati odo-
do ni ilẹ na.
6 Li ọjọ rẹ̀ ni a o gba Juda là, Israeli
yio si ma gbe li ailewu, ati eyi li orukọ ti
a o ma pè e: OLUWA ODODO WA.
7 Nitorina, sa wò o, ọjọ mbọ̀, li Oluwa
wi, ti nwọn kì yio tun wipe, Oluwa mbẹ,
ti o mu awọn ọmọ Israeli jade kuro ni ilẹ
Egipti:
8 Şugbọn pe, Oluwa mbẹ, ti o mu iru-
ọmọ ile Israeli wá, ti o si tộ wọn lati ilu
ariwa wá, ati lati ilu wọnni nibi ti mo ti lé
wọn si, nwọn o si gbe inu ilẹ wọn.
9 Si awọn woli. Ọkàn mi ti bajẹ ninu
mi, gbogbo egungun mi mì; emi dabi
ọmuti, ati ọkọnrin ti ọti-waini ti bori rẹ̀
niwaju Oluwa, ati niwaju ọ̀rọ ìwa-mimọ́
rẹ̀.
10 Nitori ilẹ na kún fun awọn panşaga;
ilẹ na nṣọ̀fọ, nitori egún, pápá oko aginju
gbẹ: irìn wọn di buburu, agbara wọn kò
si to.
11 Nitori, ati woli ati alufa, nwọn bajẹ;
pẹlupẹlu ninu ile mi ni mo ri ìwa-buburu
wọn, li Oluwa wi.
12 Nitorina ipa-ọ̀na wọn yio jẹ fun wọn
bi ibi yiyọ́ li okunkun: a o tì wọn, nwọn
o si şubu ninu rẹ̀, nitori emi o mu ibi wá
sori wọn, ani ọdun ibẹ̀wo wọn, li Oluwa
wi.
13 Emi si ti ri were ninu awọn woli
Samaria, nwọn sọ asọtẹlẹ li orukọ Baali,
nwọn si mu Israeli enia mi şina.
14 Emi ti ri irira lara awọn woli Jerusa-
lemu, nwọn şe panşaga, nwọn si rìn ninu
eke, nwọn mu ọwọ oluşe-buburu le tobẽ, ti
kò si ẹnikan ti o yipada kuro ninu ìwa-
buburu rẹ̀; gbogbo wọn dabi Sodomu ni-
waju mi, ati awọn olugbe rẹ̀ bi Gomorra.
15 Nitorina bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi niti awọn woli; Sa wò o, emi o
fi wahala bộ wọn, emi o si jẹ ki nwọn ki o
mu omi orõro: nitori lati ọdọ awọn woli
Jerusalemu ni ibajẹ ti jade lọ si gbogbo ilẹ
na.
16 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi:
Ẹ máşe feti si ọ̀rọ awọn woli ti nsọ asọtẹlẹ
fun nyin: nwọn sọ nyin di asan, nwọn
sộrọ iran inu ara wọn, kì işe lati ẹnu
Oluwa.
17 Nwọn wi sibẹ fun awọn ti o ngàn mi

Digitized by Google

pe, Oluwa ti wi pe, Alafia yio wà fun nyin;
nwọn si wi fun olukuluku ti o nrìn nipa
agidi ọkàn rẹ̀: pe, kò si ibi kan ti yio wá
sori nyin.
18 Nitori tali o duro ninu igbimọ Olu-
wa, ti o woye, ti o si gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀? tali o
kíyesi ọ̀rọ rẹ̀, ti o si gbà a gbọ́?
19 Sa wò o, afẹfẹ-ìji Oluwa! ibinu ti
jade! afẹyika ìji yio ṣubu ni ikanra si ori
awọn oluṣe buburu:
20 Ibinu Oluwa kì yio pada, titi yio fi
ṣe e, titi yio si fi mu iro inu rẹ̀ ṣẹ, li ọjọ
ikẹhin ẹnyin o mọ̀ ọ daju.
21 Emi kò ran awọn woli wọnyi, ṣugbọn
nwọn sare: emi kò ba wọn sọ̀rọ, ṣugbọn
nwọn sọ asọtẹlẹ.
22 Ibaṣepe nwọn duro ni imọran mi,
nwọn iba jẹ ki enia mi ki o gbọ́ ọ̀rọ mi,
nigbana ni nwọn iba yipada kuro ni ọ̀na
buburu wọn, ati kuro ninu buburu iṣe
wọn.
23 Emi ha iṣe Ọlọrun itosi? li Oluwa
wi, kì iṣe Ọlọrun lati okere pẹlu?
24 Ẹnikẹni le fi ara rẹ̀ pamọ ni ibi ìkọ-
kọ, ti emi kì yio ri i, li Oluwa wi. Emi
kò ha kún ọrun on aiye, li Oluwa wì?
25 Emi ti gbọ́ eyiti awọn woli sọ, ti
nwọn sọ asọtẹlẹ li orukọ mi wi pe, Mo lá
alá! mọ lá alá!
26 Yio ti pẹ to, ti eyi yio wà li ọkàn
awọn woli ti nsọ asọtẹlẹ eke? ani, awọn
alasọtẹlẹ ẹ̀tan ọkàn wọn,
27 Ti nwọn rò lati mu ki enia mi ki o
gbàgbe orukọ mi nipa alá wọn ti nwọn nrọ́,
ẹnikini fun ẹnikeji rẹ̀, gẹgẹ bi awọn baba
wọn ti gbagbe orukọ mi nitori Baali.
28 Woli na ti o lála, jẹ ki o rọ́ ọ; ati
ẹniti o ni ọ̀rọ mi, jẹ ki o fi ododo sọ ọ̀rọ
mi. Kini iyangbo ni iṣe ninu ọká, li Olu-
wa wi?
29 Ọ̀rọ mi kò ha dabi iná? li Oluwa
wi; ati bi òlu irin ti nfọ́ apata tútu?
30 Nitorina sa wò o, emi dojukọ awọn
woli, li Oluwa wi, ti o nji ọ̀rọ mi, ẹnikini
lati ọwọ ẹnikeji rẹ̀.
31 Sa wò o, emi o dojukọ awọn woli, li
Oluwa wi, ti nwọn lò ahọn wọn, ti nwọn
nsọ jade pe: O wi.
32 Sa wò o, emi dojukọ awọn ti o nsọ
asọtẹlẹ alá èke, li Oluwa wi, ti nwọn si
nrọ́ wọn, ti nwọn si mu enia mi ṣìna nipa
eke wọn, ati nipa iran wọn: ṣugbọn emi
kò rán wọn, emi kò si paṣẹ fun wọn: nito-
rina, nwọn kì yio ràn awọn enia yi lọwọ
rara, li Oluwa wi.
33 Ati nigbati awọn enia yi, tabi wọli,
tabi alufa, yio bi ọ lere wipe, kini Ọ̀rọ-
wiwo Oluwa? nigbana ni iwọ o wi fun wọn
Ọ̀rọ-wiwo ni eyi yi: Emi o tì nyin jade, li
Oluwa wi.
34 Ati woli, ati alufa, ati awọn enia, ti
yio wipe, Ọ̀rọ-wiwo Oluwa, emi o jẹ oluwa
rẹ̀ ati ile rẹ̀ ni ìya.
35 Bayi li ẹnyin o wi, ẹnikini fun ẹni-
keji, ati ẹnikan fun arakọnrin rẹ̀, pe Kini
idahùn Oluwa? ati kini ọ̀rọ Oluwa?
36 Ẹ kì o si ranti ọ̀rọ-wiwo Oluwa mọ́,
nitori ọ̀rọ olukuluku yio di ẹ̀ru wiwo fun
ontikararẹ̀; nitori ti ẹnyin ti yi ọ̀rọ Ọlọrun
alãye dà, Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun
wa.
37 Bayi ni iwọ o wi fun woli nì pe:
Idahùn wo li Oluwa fi fun ọ? ati pẹlu;
Kini Oluwa wi?
38 Ṣugbọn bi ẹnyin ba wipe, ọ̀rọ-wiwo
Oluwa, nitorina, bayi li Oluwa wi, nitori
ẹnyin nsọ ọ̀rọ yi pe, ọ̀rọ-wiwo Oluwa ti
emi si ranṣẹ si nyin pe ki ẹ máṣe wipe:
ọ̀rọ-wiwọ Oluwa;
39 Nitorina, sa wò o, Emi o gbagbe nyin
patapata, emi o si kọ̀ nyin silẹ, emi o si tì
nyin jade, ati ilu ti mo fi fun nyin ati fun
awọn baba nyin, kuro niwaju mi.
40 Emi o si mu ẹ̀gan ainipẹkun wá sori
nyin, ati itiju lailai, ti a kì yio gbagbe.

## ORI 24.

SI wò o, Oluwa fi agbọn eso-ọ̀pọtọ meji
hàn mi, ti a gbe kalẹ niwaju ile Olu-
wa, lẹhin igbati Nebukadnessari, ọba Ba-
beli, ti mu Jekoniah, ọmọ Jehoiakimu, ọba
Juda, ni ìgbekun pẹlu awọn olori Juda,
pẹlu awọn gbẹna-gbẹna, ati awọn alagbẹdẹ,
lati Jerusalemu, ti o si mu wọn wá si
Babeli.
2 Agbọn ikini ni eso-ọ̀pọtọ daradara jù,
gẹgẹ bi eso ọ̀pọtọ ti o tetekọ pọ́n: agbọn
ekeji ni eso-ọ̀pọtọ ti o buruju, ti a kò le jẹ,
bi nwọn ti buru tò.
3 Nigbana ni Oluwa wi fun mi pe, Kini
iwọ ri, Jeremiah? Emi wipe, Eso-ọ̀pọtọ,
eyi ti o dara, dara jù, ati eyi ti o buru,
buru jù, tobẽ ti a kò le jẹ ẹ, nitori nwọn
buru jù.
4 Ọro Oluwa si tọ̀ mi wá wipe,
5 Bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi; Gẹgẹ
bi eso-ọ̀pọtọ daradara wọnyi, bẹ̃li emi o fi
oju rere wò awọn ìgbekun Juda, ti emi ran
jade kuro ni ibi yi lọ si ilẹ awọn ara
Kaldea.
6 Emi o si kọju mi si wọn fun rere, emi
o si mu wọn pada wá si ilẹ yi, emi o

Digitized by Google

gbe wọn ró li aitun wó wọn lulẹ, emi o
gbìn wọn, li aitun fà wọn tu.
7 Emi o si fun wọn li ọkàn lati mọ̀ mi,
pe, Emi li Oluwa, nwọn o si jẹ enia mi,
emi o si jẹ Ọlọrun wọn, nitoripe nwọn o fi
gbogbo ọkàn wọn yipada si mi.
8 Ati gẹgẹ bi esọ-ọ̀pọtọ biburujù ti a kò
le jẹ, nitoriti nwọn burujù, bayi li Oluwa
wi, Bẹ̃ gẹgẹ ni emi o fi Sedekiah, ọba Juda,
ati awọn ijoye rẹ̀, ati awọn ti o kù ni Jeru-
salemu, ati awọn iyokù ni ilẹ yi ati awọn
ti ngbe ilẹ Egipti.
9 Emi o fi wọn fun iwọsi ati fun ibi ni-
nu gbogbo ijọba aiye, lati di ìtiju, owe,
ẹsin, ati ẹ̀gan ni ibi gbogbo, ti emi o le
wọn si.
10 Emi o si rán idà, ìyan, ati ajakalẹ-
arun, si ãrin wọn, titi nwọn o fi parun
kuro ni ilẹ eyi ti emi fi fun wọn ati fun
awọn baba wọn.

## ORI 25.

ỌRỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá nitori gbogbo
enia Juda, li ọdun kẹrin Jehoiakimu,
ọmọ Josiah, ọbà Juda, ti iṣe ọdun ikini
Nebukadnessari, ọba Babeli.
2 Eyi ti Jeremiah, woli, sọ fun gbogbo
enia Juda, ati fun awọn olugbe Jerusalemu
wipe:
3 Lati ọdun kẹtala Josiah, ọmọ Amoni,
ọba Juda, titi di oni-oloni, eyini ni, ọdun
kẹtalelogun, ọ̀rọ Oluwa ti tọ mi wá, emi
si ti sọ fun nyin, emi ndide ni kutukutu,
emi nsọ, ṣugbọn ẹnyin kò feti si i.
4 Oluwa si ti rán gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀,
awọn woli si nyin, o ndide ni kutukutu
lati rán wọn, ṣugbọn ẹnyin kò feti si i,
bẹ̃ni ẹnyin kò tẹ eti nyin silẹ lati gbọ́.
5 Wipe, ẹ sa yipada, olukuluku kuro ni
ọ̀na buburu rẹ̀, ati kuro ni buburu iṣe nyin,
ẹnyin o si gbe ilẹ ti Oluwa ti fi fun nyin,
ati fun awọn baba nyin lai ati lailai.
6 Ki ẹ má si tọ̀ ọlọrun miran lẹhin lati
ma sìn wọn, ati lati ma foribalẹ fun wọn,
ki ẹ má si ṣe fi iṣẹ ọwọ nyin mu mi binu,
emi kì yio si ṣe nyin ni ibi.
7 Ṣugbọn ẹnyin kò gbọ́ temi, li Oluwa
wi, ki ẹnyin le fi iṣẹ ọwọ nyin mu mi binu
si ibi ara nyin.
8 Nitorina, bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi: nitori ti ẹnyin kò gbọ́ ọ̀rọ mi.
9 Sa wò o, emi o ranṣẹ, emi o si mu
gbogbo idile orilẹ-ède ariwa wá, li Oluwa
wi, emi o si ranṣẹ si Nebukadnessari, ọba
Babeli, ọmọ-ọdọ mi, emi o si mu wọn wá
si ilẹ yi, ati olugbe rẹ̀, ati si gbogbo awọn
orilẹ-ède yikakiri, emi o si pa wọn pata-
pata, emi o si sọ wọn di iyanu ati iyọṣuti
si, ati ahoro ainipẹkun.
10 Pẹlupẹlu emi o mu ohùn inu-didùn,
ati ohùn ayọ̀, ohùn ọkọ-iyawo, ati ohùn
iyawo, iro okuta ọlọ, ati imọlẹ fitila kuro
lọdọ wọn.
11 Gbogbo ilẹ yi yio si di iparun ati
ahoro: orilẹ-ède wọnyi yio si sìn ọba
Babeli li ãdọrin ọdun.
12 Yio si ṣe, nigbati ãdọrin ọdun ba
pari tan, li emi o bẹ̀ ọba Babeli, ati orilẹ-
ède na, ati ilẹ awọn ara Kaldea wò, nitori
ẹ̀ṣẹ wọn; li Oluwa wi, emi o si sọ ọ di
ahoro titi lai.
13 Emi o si mu gbogbo ọ̀rọ mi wá sori
ilẹ na, ti mo ti sọ si i: ani gbogbo eyiti
a ti kọ sinu iwe yi, eyiti Jeremiah ti sọtẹlẹ
si gbogbo orilẹ-ède.
14 Nitoriti awọn wọnyi pẹlu yio mu ki
orilẹ̀-ède pupọ, ati awọn ọba nla sìn wọn:
emi o san a fun wọn gẹgẹ bi iṣe wọn ati
pẹlu gẹgẹ bi iṣẹ ọwọ wọn.
15 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli
wi fun mi: Gba ago ọti-waini ibinu mi yi
kuro lọwọ mi, ki o si jẹ ki gbogbo orilẹ-
ède ti emi o rán ọ si, mu u.
16 Ki nwọn mu, ki nwọn si ma ta gbọ̀n-
gbọn, ki nwọn si di aṣiwere, nitori idà
ti emi o rán si ãrin wọn.
17 Nigbana ni mo gba ago na li ọwọ
Oluwa, emi si jẹ ki gbogbo orilẹ-ẹ̀de, ti
Oluwa rán mi si, mu u.
18 Ani Jerusalemu ati ilu Juda wọnni,
ati awọn ọba wọn pẹlu awọn ijoye, lati sọ
wọn di ahoro, idãmu, ẹsin, ati egún, gẹgẹ
bi o ti ri loni.
19 Farao, ọba Egipti, ati awọn iranṣẹ
rẹ̀, ati awọn ijoye rẹ̀, ati gbogbo enia rẹ̀.
20 Ati gbogbo awọn enia ajeji, ati gbo-
gbo ọba ilẹ Usi, gbogbo ọba ilẹ Filistia,
ati Aṣkeloni, ati Gasa, ati Ekroni, ati
awọn iyokù Aṣdodi,
21 Edomu, ati Moabu, ati awọn ọmọ
Ammoni,
22 Ati gbogbo awọn ọba Tire, ati gbo-
gbo awọn ọba Sidoni, ati awọn ọba erekuṣu
wọnni ti mbẹ ni ikọja okun,
23 Dedani, ati Tema, ati Busi, ati gbo-
gbo awọn ti nda òṣu.
24 Ati gbogbo awọn ọba Arabia, pẹlu
awọn ọba awọn enia ajeji ti ngbe inu aginju.
25 Ati gbogbo awọn ọba Simri, ati gbo-
gbo awọn ọba Elamu, ati gbogbo awọn ọba
Medea.

Digitized by Google

26 Ati gbogbo awọn ọba ariwa, ti itosi
ati ti ọ̀na jijin, ẹnikini pẹlu ẹnikeji rẹ̀, ati
gbogbo ijọba aiye, ti mbẹ li oju aiye, ọba
Ṣeṣaki yio si mu lẹhin wọn.
27 Iwọ o si wi fun wọn pe: Bayi li
Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi;
Ẹ mu, ki ẹ si mu amuyo, ki ẹ bì, ki ẹ si
ṣubu, ki ẹ ma si le dide mọ́, nitori idà ti
emi o rán sãrin nyin.
28 Yio si ṣe, bi nwọn ba kọ̀ lati gba ago
lọwọ rẹ lati mu, ni iwọ o si wi fun wọn
pe: Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi; ni
mimu ẹnyin o mu!
29 Sa wò o, nitori ti emi bẹrẹ si imu
ibi wá sori ilu na ti a pè li orukọ mi, ẹnyin
fẹ ijẹ alaijiya? ẹnyin kì yio ṣe alaijiya:
nitori emi o pè fun idà sori gbogbo olugbe
aiye, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
30 Njẹ iwọ sọ asọtẹlẹ gbogbo ọ̀rọ wọnyi
fun wọn, ki o si wi fun wọn pe, Oluwa yio
kọ lati oke wá, yio si fọ ohùn rẹ̀ lati
ibugbe rẹ̀ mimọ́, ni kikọ, yio kọ sori
ibugbe rẹ̀, yio pariwo sori gbogbo olugbe
aiye, bi awọn ti ntẹ ifunti.
31 Igbe kan yio wá titi de opin ilẹ aiye;
nitori Oluwa ni ijà ti yio ba awọn orilẹ-ède
ja, yio ba gbogbo ẹran-ara wijọ, yio fi awọn
oluṣe-buburu fun idà, li Oluwa wi.
32 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, sa
wò o, ibi yio jade lati orilẹ-ède de orilẹ-
ède, ìji nlanla yio ru soke lati agbegbe
aiye.
33 Awọn ti Oluwa pa yio wà li ọjọ na
lati ipẹkun kini aiye titi de ipẹkun keji
aiye, a kì yio ṣọ̀fọ wọn, a kì yio ko wọn
jọpọ, bẽni a kì yio sin wọn, nwọn o di
àtan lori ile.
34 Ke! ẹnyin oluṣọ-agutan! ki ẹ si
sọkun! ẹ fi ara nyin yilẹ ninu ẽru, ẹnyin
ọlọla agbo-ẹran! nitori ọjọ a ti pa nyin ati
lati tú nyin ka pe, ẹnyin o si ṣubu bi
ohun-elo iyebiye.
35 Sisa kì yio si fun awọn oluṣọ-agutan,
bẽni asalà kì yio si fun awọn ọlọla agbo-
ẹran.
36 Ohùn ẹkun awọn oluṣọ-agutan, ati
igbe awọn ọlọla agbo-ẹran li a o gbọ́:
nitori Oluwa bà papa-oko tutu wọn jẹ.
37 Ibùgbe alafia li o di ahoro, niwaju
ibinu kikan Oluwa.
38 O ti fi pantiri rẹ̀ silẹ bi kiniun nitori
ti ilẹ wọn di ahoro, niwaju ibinu idà ani-
nilara, ati niwaju ibinu kikan rẹ̀.

## ORI 26.

NI ibẹrẹ ijọba Jehoiakimu, ọmọ Josiah,
ọba Juda, ni ọ̀rọ yi ti ọdọ Oluwa wá
wipe;
2 Bayi li Oluwa wi, Duro ni àgbala
ile Oluwa, ki o si sọ fun gbogbo ilu Juda
ti o wá lati sìn ni ile Oluwa gbogbo ọ̀rọ
ti mo pa laṣẹ fun ọ lati sọ fun wọn: máṣe
ke ọ̀rọ kanṣoṣo kù:
3 Bi o ba jẹ pe, nwọn o gbọ́, ti oluku-
luku yio yipada kuro li ọ̀na buburu rẹ̀, ki
emi ki o le yi ọkàn pada niti ibi ti emi
rò lati ṣe si wọn, nitori iṣe buburu wọn.
4 Iwọ o si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa
wi: bi ẹnyin kì yio feti si mi lati rin ninu
ofin mi, ti emi ti gbe kalẹ niwaju nyin.
5 Lati gbọ́ ọ̀rọ awọn ọmọ-ọdọ mi, awọn
woli, ti emi rán si nyin, ti mo ndide ni
kutukutu, ti mo rán wọn; ṣugbọn ẹnyin
kò gbọ́.
6 Emi o si ṣe ile yi bi Ṣilo, emi o si ṣe
ilu yi ni ifibu si gbogbo orilẹ-ède aiye.
7 Nigbana ni awọn alufa, ati awọn wọli,
ati gbogbo enia gbọ́, bi Jeremiah ti nsọ
ọ̀rọ wọnyi ni ile Oluwa.
8 O si ṣe nigbati Jeremiah pari gbogbo
ọ̀rọ ti Oluwa paṣẹ fun u lati sọ fun gbogbo
enia, nigbana ni awọn alufa, ati awọn woli,
ati gbogbo enia di i mu wipe, kikú ni iwọ
o kù!
9 Ẽṣe ti iwọ sọ asọtẹlẹ li orukọ Oluwa
wipe, Ile yi yio dabi Ṣilo, ati ilu yi yio
di ahoro laini olugbe? Gbogbo enia kojọ
pọ̀ tì Jeremiah ni ile Oluwa.
10 Nigbati awọn ijoye Juda gbọ́ nkan
wọnyi, nwọn jade lati ile ọba wá si ile
Oluwa, nwọn si joko li ẹnu-ọ̀na titun ile
Oluwa.
11 Awọn alufa ati awọn woli wi fun
awọn ijoye, ati gbogbo enia pe, Ọkọnrin
yi jẹbi ikú nitoriti o sọ asọtẹlẹ si ilu yi, bi
ẹnyin ti fi eti nyin gbọ́.
12 Nigbana ni Jeremiah wi fun awọn
ijoye ati gbogbo enia pe, Oluwa rán mi
lati sọ asọtẹlẹ gbogbo ọ̀rọ ti ẹnyin gbọ́, si
ile yi ati si ilu yi.
13 Njẹ nisisiyi, ẹ tun ọ̀na nyin ati iṣe
nyin ṣe, ki ẹ si gbọ́ ohùn Oluwa Ọlọrun
nyin; Oluwa yio si yi ọkàn rẹ̀ pada niti
ibi ti o sọ si nyin.
14 Bi o ṣe ti emi, sa wò o, emi mbẹ li
ọwọ nyin: ẹ ṣe si mi, gẹgẹ bi o ti dara ti
o si yẹ loju nyin.
15 Sibẹ, ẹ mọ̀ eyi daju pe, bi ẹ ba pa
mi, mimu ni ẹnyin o mu ẹ̀jẹ alaiṣẹ wá sori

Digitized by Google

nyin ati sori ilu yi, ati sori awọn olugbe
rẹ: nitori li otitọ Oluwa li o rán mi si
nyin lati sọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi li eti nyin.
16 Nigbana ni awọn ijoye ati gbogbo
enia sọ fun awọn alufa ati awọn woli pe,
Ọkọnrin yi kò yẹ lati kú; nitoriti o sọ̀rọ
fun wa li orukọ Oluwa, Ọlọrun wa.
17 Awọn ọkọnrin kan ninu awọn àgba
nã si dide, nwọn si sọ fun gbogbo ijọ ẹnia
wipe:
18 Mikah, ara Moraṣi, ṣe woli li ọjọ
Hesekiah, ọba Juda, o si wi fun gbogbo
enia Juda pe: Bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi: a o tulẹ Sioni fun oko, Jeru-
salemu yio di òkiti alapa, ati oke ile yi
gẹgẹ bi ibi giga igbo.
19 Njẹ, Hesekiah, ọba Juda, ati gbogbo
Juda ha pa a bi? Ẹ̀ru Oluwa kò ha bà a,
kò ha bẹ Oluwa bi? Oluwa si yi ọkàn
pada niti ibi ti o ti sọ si wọn; Bayi li awa
iba ṣe mu ibi nla wá sori ẹmi wa?
20 Ọkọnrin kan si wà ẹ̀wẹ, ti o sọ asọtẹlẹ
ni orukọ Oluwa, ani Urijah, ọmọ Ṣemaiah,
ara Kirjatjearimu, ti o sọ asọtẹlẹ si ilu yi,
ati si ilẹ yi, gẹgẹ bi gbogbo ọ̀rọ Jeremiah.
21 Ati nigbati Jehoiakimu, ọba, pẹlu
gbogbo ọkọnrin alagbara rẹ̀, ati awọn ijoye
gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀, ọba nwá a lati pa; ṣugbọn
nigbati Urijah gbọ́, o bẹ̀ru, o salọ, o si wá
si Egipti.
22 Jehoiakimu, ọba, si rán enia lọ si
Egipti, ani Elnatani, ọmọ Akbori ati enia
miran pẹlu rẹ̀ lọ si Egipti.
23 Nwọn si mu Urijah lati Egipti tọ
Jehoiakimu ọba wá; ẹni ti o fi idà pa
a, o si sọ okú rẹ̀ sinu isa-okú awọn enia
lasan.
24 Bẽni ọwọ Ahikamu, ọmọ Safani mbẹ
pẹlu Jeremiah, ki nwọn ki o má ba fi i le
awọn enia lọwọ lati pa.

## ORI 27.

LI atetekọbẹrẹ ijọba Sedekiah, ọmọ Josiah,
ọba Juda, li ọ̀rọ yi tọ̀ Jeremiah wá lati
ọ̀dọ Oluwa wipe,
2 Bayi li Oluwa wi fun mi; Ṣe ijara ati
àjaga-ọrùn fun ara rẹ, ki o si fi wọ ọrùn
rẹ.
3 Ki o rán wọn lọ si ọdọ ọba Edomu,
ati si ọba Moabu, ati si ọba awọn ọmo Am-
moni, ati si ọba Tire, ati si ọba Sidoni,
lọwọ awọn ikọ̀ ti o wá si Jerusalemu sọdọ
Sedekiah, ọba Juda.
4 Ki o si paṣẹ fun wọn lati wi fun awọn
oluwa wọn pe, Bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun, Ọlọrun Israeli, wi, Bayi li ẹnyin o
wi fun awọn oluwa nyin pe;
5 Emi ti dá aiye, enia ati ẹranko ti o wà
lori ilẹ aiye, nipa agbara nla mi, ati nipa
ọwọ ninà mi, emi si fi i fun ẹnikẹni ti o wù
mi.
6 Njẹ nisisiyi, emi fi gbogbo ilẹ yi le
ọwọ Nebukadnessari, ọba Babeli, ọmọ-ọdọ
mi: ati ẹranko igbẹ ni mo fi fun u pẹlu
lati sin i.
7 Ati orilẹ-ède gbogbo ni yio sin on, ati
ọmọ rẹ̀ ati ọmọ-ọmọ rẹ̀, titi di igba ti akoko
ilẹ tirẹ̀ yio de; lara rẹ̀ ni orilẹ-ède pipọ ati
awọn ọba nla yio jẹ.
8 Yio si ṣe, orilẹ-ède ati ijọba ti kì yio
sin Nebukadnessari ọba Babeli, ti kì yio fi
ọrùn wọn si abẹ àjaga ọba Babeli, orilẹ-ède
na li emi o fi idà, ati iyan, ati ajakalẹ-arun,
jẹ niya, li Oluwa wi, titi emi o fi run wọn
nipa ọwọ rẹ̀.
9 Nitorina ẹ máṣe fi eti si awọn woli
nyin, tabi si awọn alafọṣẹ nyin, tabi si
awọn alála, tabi si awọn oṣo nyin, tabi
awọn ajẹ nyin ti nsọ fun nyin pe, Ẹnyin
kì o sin ọba Babeli:
10 Nitori nwọn sọ-asọtẹlẹ eke fun nyin,
lati mu nyin jina réré kuro ni ilẹ nyin, ki
emi ki o lè lé nyin jade, ti ẹnyin o si ṣegbe.
11 Ṣugbọn orilẹ-ède na ti o mu ọrùn rẹ̀
wá si abẹ àjaga ọba Babeli, ti o si sin i, on
li emi o jẹ ki o joko ni ilẹ wọn, li Oluwa
wi, yio si ro o, yio si gbe ibẹ.
12 Emi si wi fun Sedekiah, ọba Juda,
gẹgẹ bi ọ̀rọ wọnyi, pe, Ẹ mu ọrùn nyin si
abẹ àjaga ọba Babeli, ki ẹ sin i, pẹlu awọn
enia rẹ̀, bẽli ẹnyin o yè.
13 Ẽṣe ti ẹnyin o kú, iwọ, ati enia rẹ,
nipa idà, ati iyan, ati ajakalẹ-arun, bi
Oluwa ti sọ si orilẹ-ède ti kì yio sin ọba
Babeli.
14 Ẹ máṣe gbọ́ ọ̀rọ awọn wọli ti nwọn
nsọ fun nyin wipe, Ẹnyin kì yio sin ọba
Babeli, nitori nwọn sọ asọtẹlẹ eke fun
nyin.
15 Nitori emi kò rán wọn, li Oluwa wi,
ṣugbọn nwọn nsọ asọtẹlẹ eke li orukọ mi:
ki emi ki o lè lé nyin jade, ki ẹ ṣegbe,
ẹnyin, pẹlu awọn woli ti o sọ asọtẹlẹ fun
nyin.
16 Pẹlupẹlu emi sọ fun awọn alufa ati
fun gbogbo enia yi wipe, Bayi li Oluwa wi,
Ẹ má gbọ́ ọ̀rọ awọn woli ti nsọ asọtẹlẹ
fun nyin wipe, Sa wò o, ohun-èlo ile Olu-
wa li a o mu pada li aipẹ nisisiyi lati
Babẹli wá: nitori nwọn sọ asọtẹlẹ eke fun
nyin.

Digitized by Google

17 Ẹ máṣe gbọ́ ti wọn ; ẹ sin ọba Babeli,
ẹ si yè : ēṣe ti ilu yi yio fi di ahoro ?
18 Ṣugbọn bi nwọn ba ṣe woli, ati bi ọ̀rọ
Oluwa ba wà pẹlu wọn, jẹ ki nwọn ki o
bẹbẹ lọdọ Oluwa awọn ọmọ-ogun, ki ohun-
èlo iyokù ni ile Oluwa ati ni ile ọba Juda,
ati ni Jerusalemu, ki nwọn ki o máṣe lọ si
Babeli.
19 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi niti opó mejeji, ati niti agbada nla, ati
niti ipilẹṣẹ, ati niti ohun-èlo iyokù ti o kù
ni ilu yi.
20 Eyi ti Nebukadnessari, ọba Babeli,
kò mu lọ nigbati o mu Jekoniah, ọmọ
Jehoiakimu, ọba Juda, ni igbèkun lati Je-
rusalemu lọ si Babeli, pẹlu gbogbo awọn
ọlọla Juda ati Jerusalemu ;
21 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun,
Ọlọrun Israeli, wi, niti ohun-èlo ti o kù
ni ile Oluwa, ati ni ile ọba Juda ati
Jerusalemu.
22 A o kó wọn lọ si Babeli, nibẹ ni
nwọn o wà titi di ọjọ na ti emi o bẹ̀ wọn
wò, li Oluwa wi, emi o si mu wọn goke wá,
emi o si mu wọn pada wá si ibi yi.

## ORI 28.

O SI ṣe li ọdun kanna li atetekọbẹrẹ ijọba
Sedekiah, ọba Juda, li ọdun kẹrin ati
oṣù karun, ti Hananiah, ọmọ Asuri woli,
ti iṣe ti Gibeoni, wi fun mi ni ile Oluwa,
niwaju awọn alufa ati gbogbo enia pe,
2 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun
Israeli wi, pe, Emi ti ṣẹ àjaga ọba Babeli.
3 Ninu akoko ọdun meji li emi o tun
mu gbogbo ohun-èlo ile Oluwa pada wá
si ibi yi, ti Nebukadnessari, ọba Babeli,
kó kuro ni ibi yi, ti o si mu wọn lọ si
Babeli.
4 Emi o si tun mu Jekoniah, ọmọ Je-
hoiakimu, ọba Juda, pẹlu awọn igbekun
Juda, ti o ti lọ si Babeli pada wá si ibi yi,
li Oluwa wi, nitori emi o si ṣẹ àjaga ọba
Babeli.
5 Jeremiah woli si wi fun Hananiah
woli niwaju awọn alufa ati niwaju gbogbo
enia, ti o duro ni ile Oluwa pe :
6 Jeremiah woli si wipe, Amin : ki Olu-
wa ki o ṣe bẹ̃ : ki Oluwa ki o mu ọ̀rọ rẹ ti
iwọ sọ asọtẹlẹ ṣẹ, lati mu ohun-elo ile Olu-
wa ati gbogbo igbekun pada, lati Babeli
wá si ibi yi.
7 Ṣugbọn nisisiyi, iwọ gbọ́ ọ̀rọ yi ti mo
sọ si eti rẹ ati si eti enia gbogbo.
8 Awọn woli ti o ti ṣaju mi, ati ṣaju rẹ
ni igbãni sọ asọtẹlẹ pupọ, ati si ijọba nla
niti ogun, ati ibi, ati ajakalẹ-arun.
9 Woli nì ti o sọ asọtẹlẹ alafia, bi ọ̀rọ
woli na ba ṣẹ, nigbana ni a o mọ̀ woli na
pe, Oluwa rán a nitõtọ.
10 Nigbana ni Hananiah woli mu àjaga
kuro li ọrùn Jeremiah woli o si ṣẹ́ ẹ.
11 Hananiah si wi niwaju gbogbo enia
pe, Bayi li Oluwa wi ; Bẽ gẹgẹ li emi o ṣẹ́
ajaga Nebukadnessari, ọba Babeli, kuro li
ọrùn orilẹ-ède gbogbo ni igba ọdun meji.
Jeremiah woli si ba ọ̀na tirẹ̀ lọ.
12 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Jeremiah
woli wá lẹhin igbati Hananiah woli ti ṣẹ́
ajaga kuro li ọrùn Jeremiah woli, wipe,
13 Lọ isọ fun Hananiah wipe, Bayi li
Oluwa wi ; Iwọ ti ṣẹ́ àjaga igi ; ṣugbọn
iwọ o si ṣe àjaga irin ni ipo wọn.
14 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun,
Ọlọrun Israeli wi : emi ti fi ajaga irin si
ọrùn gbogbo orilẹ-ède wọnyi, ki nwọn ki
o sin Nebukadnessari, ọba Babeli, nwọn
o si sin i, emi si fi ẹranko igbẹ fun u
pẹlu.
15 Nigbana ni Jeremiah, woli, wi fun
Hananiah, woli, pe, Gbọ́ nisisiyi, Hanan-
iah ; Oluwa kò rán ọ ; ṣugbọn iwọ jẹ ki
enia yi ki o gbẹkẹle eke.
16 Nitorina bayi li Oluwa wi ; Sa wo
o, emi o ta ọ nù kuro loju aiye : li ọdun
yi ni iwọ o kú, nitori iwọ ti sọ̀rọ iṣọtẹ si
Oluwa.
17 Bẽni Hananiah woli si kú li ọdun na
li oṣu keje.

## ORI 29.

WỌNYI si li ọ̀rọ iwe ti Jeremiah woli
rán lati Jerusalemu si iyokù ninu
awọn àgba ti o wà ni igbèkun, ati si awọn
alufa, ati awọn woli, ati si gbogbo enia ti
Nebukadnessari kó ni igbekun lọ lati Jeru-
salemu si Babeli.
2 Lẹhin igbati Jekoniah, ọba, ati ayaba,
ati awọn iwẹfa, ati awọn ijoye Juda ati
Jerusalemu, ati awọn gbẹnagbẹna pẹlu awọn
alagbẹdẹ ti fi Jerusalemu silẹ lọ.
3 Nipa ọwọ Elasa, ọmọ Ṣafani, ati Ge-
mariah, ọmọ Ḥilkiah, (ẹniti Sedekiah, ọba
Juda, rán si Babeli tọ Nebukadnessari, ọba
Babeli) wipe,
4 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun
Israeli, wi fun gbogbo awọn ti a kó ni
igbekun lọ, ti emi mu ki a kó lọ lati Jeru-
salemu si Babeli ;
5 Ẹ kọ́ ile ki ẹ si ma gbe inu wọn ; ẹ
gbìn ọgba, ki ẹ si mã jẹ eso wọn ;

Digitized by Google

6 Ẹ fẹ́ aya, ki ẹ si bi ọmọkọnrin ati ọmọbirin; ki ẹ si fẹ́ aya fun awọn ọmọ nyin, ẹ si fi awọn ọmọbirin nyin fun ọkọ, ki nwọn ki o le mã bi ọmọkọnrin ati ọmọbirin; ki ẹ le mã pọ si i nibọ, ki ẹ má si bùkun.

7 Ki ẹ si mã wá alafia ilu na, nibiti emi ti mu ki a kò nyin lọ ni igbekun, ẹ si mã gbadura si Oluwa fun u: nitori ninu alafia rẹ̀ li ẹnyin o ni alafia.

8 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọgun, Ọlọrun Israeli, wi pe, Ẹ máṣe jẹ ki awọn woli nyin ti o wá lãrin nyin ati awọn alafọṣẹ nyin tàn nyin jẹ, ki ẹ má si feti si alá nyin ti ẹnyin lá.

9 Nitori nwọn sọ asọtẹlẹ eke fun nyin li orukọ mi: emi kò rán wọn, li Oluwa wi.

10 Nitori bayi li Oluwa wi pe, Lẹhin ti ãdọrin ọdun ba pari ni Babeli, li emi o bẹ̀ nyin wò, emi o si mu ọ̀rọ rere mi ṣẹ si nyin, ni mimu nyin pada si ibi yi.

11 Nitori emi mọ̀ ìro ti mo rò si nyin, li Oluwa wi, ani ìro alafia, kì si iṣe fun ibi, lati fun nyin ni ìgba ikẹhin ati ireti.

12 Ẹnyin o si kepe mi, ẹ o si lọ, ẹ o si gbadura si mi, emi o si tẹti si nyin.

13 Ẹnyin o si ṣafẹri mi, ẹ o si ri mi, nitori ẹ o fi gbogbo ọkàn nyin wá mi.

14 Emi o di rírì fun nyin, li Oluwa wi: emi o si yi igbekun nyin pada kuro, emi o si kó nyin jọ lati gbogbo orilẹ-ède ati lati ibi gbogbo wá, nibiti emi ti lé nyin lọ, li Oluwa wi; emi o si tun mu nyin wá si ibi ti mo ti mu ki a kó nyin ni igbekun lọ.

15 Nitoriti ẹnyin ti wipe, Oluwa ti gbe awọn woli kalẹ fun wa ni Babeli:

16 Pe, Bayi li Oluwa wi niti ọba ti o joko lori itẹ́ Dafidi, ati niti gbogbo enia, ti ngbe ilu yi, ani niti awọn arakọnrin nyin ti kò jade lọ pẹlu nyin sinu igbekun.

17 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi; Wò o, emi o rán idà sarin wọn, ìyan, ati àjakalẹ-àrun, emi o ṣe wọn bi eso-ọpọtọ buburu, ti a kò le jẹ, nitori nwọn buru.

18 Emi o si fi idà, ìyan, ati àjakalẹ-arun lepa wọn; emi o si fi wọn fun iwọsi ni gbogbo ijọba aiye, fun egún, ati iyanu, ati ẹsin, ati ẹ̀gan, lãrin gbogbo orìlẹ-ède, nibiti emi o le wọn si.

19 Nitoriti nwọn kò gbọ́ ọ̀rọ mi, li Oluwa wi, ti emi rán si wọn nipa awọn ọmọọdọ mi, awọn woli, emi dide ni kutukutu mo si rán wọn; ṣugbọn ẹnyin kò fẹ igbọ́, li Oluwa wi.

20 Njẹ ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, gbogbo ẹnyin igbekun ti emi ti ran jade lati Jerusalemu si Babeli.

21 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi, niti Ahabu ọmọ Kolaiah, ati niti Sedekiah ọmọ Maaseiah, ti nsọtẹlẹ eke fun nyin li orukọ mi; wò o, emi fi wọn le ọwọ Nebukadnessari, ọba Babeli; on o si pa wọn li oju nyin;

22 Ati lati ọdọ wọn li a o da ọ̀rọ-egún kan silẹ li ẹnu gbogbo igbekun Juda ti o wà ni Babeli, wipe: Ki Oluwa ki o ṣe ọ bi Sedekiah, ati bi Ahabu, awọn ẹniti ọba Babeli sun ninu iná.

23 Nitori nwọn ti hùwa, wère ni Israeli, nwọn si ba aya aladugbo wọn ṣe panṣaga, nwọn si ti sọrọ eke li orukọ mi, ti emi kò ti pa li aṣẹ fun wọn: emi tilẹ mọ̀, emi si li ẹlẹri, li Oluwa wi.

24 Ati fun Ṣemaiah ara Nehalami, ni iwọ o sọ wipe.

25 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli wi pe, Nitoripe iwọ ti rán iwe li orukọ rẹ si gbogbo enia ti o wà ni Jerusalemu ati si Sefaniah, ọmọ Maaseiah, alufa, ati si gbogbo awọn alufa, wipe,

26 Oluwa ti fi ọ jẹ oyè alufa ni ipo Jehoiada, alufa, ki ẹnyin ki o lè jẹ olutọju ni ile Oluwa, nitori olukuluku aṣiwere enia, ati ẹnikẹni ti o sọ asọtẹlẹ ki iwọ ki o le fi wọn sinu tubu ati sinu àba.

27 Njẹ nisisiyi, ẽṣe ti iwọ kò ba Jeremiah ti Anatoti wi, ẹniti o nsọ asọtẹlẹ fun nyin!

28 Nitorina li o ṣe ranṣẹ si wa ni Babeli, wipe, Akoko yio pẹ: ẹ kọ ile, ki ẹ si ma gbe inu wọn, ẹ si gbìn ọgbà, ki ẹ ma jẹ eso wọn.

29 Sefaniah, alufa, si ka iwe yi li eti Jeremiah woli.

30 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ Jeremiah wá wipe,

31 Ranṣẹ si gbogbo awọn igbekun, wipe, Bayi li Oluwa wi niti Ṣemaiah, ara Nehalami, nitoripe Ṣemaiah ti sọtẹlẹ fun nyin, ṣugbọn emi kò ran a, ti on si mu nyin gbẹkẹle eke:

32 Nitorina, bayi li Oluwa wi: Wò o, emi o bẹ Ṣemaiah, ara Nehalami, wò, ati iru-ọmọ rẹ̀; on kì yio ni ọkọnrin kan lati ma gbe ãrin enia yi; bẹ̃ni kì yio ri rere na ti emi o ṣe fun awọn enia mi, li Oluwa wi; nitoripe o ti ṣọtẹ si Oluwa.

## ORI 30.

Ọ̀RỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa wá, wipe,

2 Bayi li Oluwa, Ọlọrun Israeli wi, pe,

Digitized by Google

Iwọ kọ gbogbo ọ̀rọ ti mo ti ba ọ sọ sinu
iwe kan.
3 Nitori kiyesi i, ọjọ mbọ, li Oluwa wi,
ti emi o mu igbekun awọn enia mi, Israeli
ati Juda, pada, li Oluwa wi: emi o si mu
ki nwọn pada bọ̀ si ilẹ ti emi fi fun awọn
baba wọn, nwọn o si ni i.
4 Wọnyi si li ọ̀rọ ti Oluwa sọ niti Israeli
ati niti Juda.
5 Nitori bayi li Oluwa wi; Awa ti gbọ́
ohùn ìwa-riri, ẹ̀ru, kì si iṣe ti alafia.
6 Ẹnyin sa bere, ki ẹ si ri bi ọkọnrin a
ma rọbi ọmọ: Ẽṣe ti emi fi ri gbogbo awọn
ọkọnrin pẹlu ọwọ wọn li ẹgbẹ wọn, bi
obirin ti nrọbi, ti a si sọ gbogbo oju di
jijoro?
7 Oṣe! nitori ọjọ na tobi, tobẽ ti kò si
ọkan bi iru rẹ̀: o jẹ àkoko wahala fun
Jakobu; sibẹ a o gbà a kuro ninu rẹ̀.
8 Yio si ṣe li ọjọ na, li Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi, ti emi o si ṣẹ àjaga kuro li
ọrùn rẹ, emi o si ja ìde rẹ, awọn alejo kì
yio si mu ọ sìn wọn mọ:
9 Sugbọn nwọn o ma sin Oluwa Ọlọrun
wọn, ati Dafidi ọba wọn, ẹniti emi o gbe
kalẹ fun wọn.
10 Njẹ nisisiyi, má bẹ̀ru, iwọ Jakobu,
ọmọ-ọdọ mi, li Oluwa wi; ki o má si fòya,
iwọ Israeli: nitorina sa wò o, emi o gbà
ọ lati okere wá, ati iru-ọmọ rẹ lati igbe-
kun wọn; Jakobu yio si pada, yio si wà
ni isimi, yio si gbe jẹ, ẹnikan kì yio si
dẹruba a.
11 Nitori emi wà pẹlu rẹ, li Oluwa wi,
lati gbà ọ: bi emi tilẹ ṣe ipari patapata ni
gbogbo orilẹ-ède, nibiti emi ti tu ọ ka si,
sibẹ emi kì yio ṣe ọ pari patapata: ṣugbọn
emi o ba ọ wi ni ìwọn, emi kì o jọ̃ rẹ lọwọ
li alaijiya.
12 Nitori bayi li Oluwa wi, Ifarapa rẹ jẹ
aiwotan, ọgbẹ rẹ si jẹ aijina.
13 Kò si ẹniti o gba ọ̀ran rẹ rò, lati dì i,
ọja imularada kò si.
14 Gbogbo awọn olufẹ rẹ ti gbagbe rẹ;
nwọn kò tẹle ọ; nitori ìlù ọta li emi o lù
ọ, ni inà alaini ãnu, nitori ọ̀pọlọpọ aiṣedede
rẹ, nitori ẹ̀ṣẹ rẹ pọ si i,
15 Ẽṣe ti iwọ nkigbe nitori ifarapa rẹ?
ikãnu rẹ jẹ aiwotan, nitori ọ̀pọlọpọ aiṣe-
dede rẹ; ẹ̀ṣẹ rẹ si pọ̀ si i, nitorina ni emi
ti ṣe ohun wọnyi si ọ.
16 Nitorina gbogbo awọn ti o jẹ ọ, li a
o jẹ; ati gbogbo awọn ọta rẹ, olukuluku
wọn, ni yio lọ si igbekun: ati awọn ti o
kó ọ yio di kikó, ati gbogbo awọn ti o fi ọ
ṣe ijẹ li emi o fi fun ijẹ.
17 Nitori emi o fi ọja imularada lẹ̀ ọ,
emi o si wò ọgbẹ rẹ san, li Oluwa wi; ni-
tori nwọn pè ọ li ẹniti a le jade; Sioni, ti
ẹnikan kò ṣafẹri rẹ̀!
18 Bayi li Oluwa wi; Wò o, emi o tun
mu igbekun agọ Jakobu pada bọ̀; emi o si
ṣãnu fun ibugbe rẹ̀; a o si kọ́ ilu na sori
okiti rẹ̀, a o si ma gbe ãfin gẹgẹ bi ilana
rẹ̀.
19 Ati lati inu wọn ni ọpẹ́ ati ohùn
awọn ti nyọ̀ yio ti jade: emi o si mu wọn
bi si i, nwọn kì o si jẹ diẹ; emi o ṣe wọn
li ogo pẹlu, nwọn kì o si kere.
20 Awọn ọmọ wọn pẹlu yio ri bi ti iṣaju,
ijọ wọn li a o fi idi rẹ̀ mulẹ niwaju mi,
emi o si jẹ gbogbo awọn ti o ni wọn lara
niya.
21 Ọlọla rẹ̀ yio si jẹ lati inu ara wọn wá,
alakoso rẹ̀ lati ãrin rẹ̀; emi o si mu u
sunmọ tosi, on o si sunmọ ọdọ mi: nitori
tani ẹniti o mura ọkàn rẹ̀ lati sunmọ ọdọ
mi? li Oluwa wi.
22 Ẹnyin o si jẹ enia mi, emi o si jẹ
Ọlọrun nyin.
23 Wò o, afẹfẹ iji Oluwa! ibinu ti jade!
afẹyika ìji yio ṣubu ni ikanra si ori oluṣe-
buburu.
24 Ibinu kikan Oluwa kì o pada, titi on
o fi ṣe e, ati titi on o fi mu ìro ọkàn rẹ̀ ṣẹ:
li ọjọ ikẹhin ẹnyin o mọ̀ ọ daju.

## ORI 31.

LI àkoko na, li Oluwa wi, li emi o jẹ
Ọlọrun gbogbo idile Israeli, nwọn o si
jẹ enia mi.
2 Bayi li Oluwa wi, Enia ti o sala lọwọ
idà ri ore-ọfẹ li aginju, ani Israeli nigbati
emi lọ lati mu u lọ si isimi rẹ̀.
3 Oluwa ti fi ara hàn fun mi lati okere!
pe, Nitõtọ emi fi ifẹni aiyeraiye fẹ ọ, nito-
rina ni emi ti ṣe pa ore-ọfẹ mọ fun ọ.
4 Emi o tun ọ kọ́, iwọ o si di kikọ, iwọ
wundia Israeli! iwọ o si fi timbreli rẹ ṣe
ara rẹ lọṣọ, iwọ o si jade lọ ni ọwọ́-ijo ti
awọn ti nyọ̀.
5 Iwọ o gbìn ọgba-ajara sori oke Sa-
maria: awọn àgbẹ yio gbìn i, nwọn o si
jẹ ẹ.
6 Nitori ọjọ na ni eyi, ti awọn oluṣọ
lori oke Efraimu yio kigbe pe, Ẹ dide, ẹ si
jẹ ki a goke lọ si Sioni sọdọ Oluwa, Ọlọrun
wa.
7 Nitori bayi li Oluwa wi; ẹ fi ayọ̀ kọrin
didún fun Jakobu, ẹ si ho niti olori awọn
orilẹ-ède: ẹ kede! ẹ yìn, ki ẹ si wipe:
Oluwa, gbà awọn enia rẹ la, iyokù Israeli!

Digitized by Google

8 Wò o, emi o mu wọn lati ilẹ ariwa wá,
emi o si kó wọn jọ lati àgbegbe ilẹ aiye,
afọju ati ayarọ pẹlu wọn, aboyun ati ẹniti
nrọbi ṣọkan pọ̀: li ẹgbẹ nlanla ni nwọn o
pada sibẹ.
9 Nwọn o wá pẹlu ẹkun, pẹlu adura li
emi o si ṣe amọ̀na wọn: emi o mu wọn rìn
lẹba odò omi li ọ̀na ganran, nwọn kì yio
kọsẹ ninu rẹ̀: nitori emi jẹ baba fun Is-
raeli, Efraimu si li akọbi mi.
10 Ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, ẹnyin orilẹ-ède, ẹ
sọ ọ ninu erekuṣu òkere, ki ẹ si wipe, Ẹniti
o tú Israeli ka yio kó o jọ, yio si pa a mọ,
gẹgẹ bi oluṣọ-agutan agbo-ẹran rẹ̀.
11 Nitori Oluwa ti tú Jakobu silẹ, o si
rà a pada li ọwọ awọn ti o li agbara jù u lọ.
12 Njẹ, nwọn o wá nwọn o si kọrin ni
ibi giga Sioni, nwọn o si jumọ lọ sibi ore
Oluwa, ani fun alikama, ati fun ọti-waini,
ati fun ororo, ati fun ẹgbọrọ agbo-ẹran, ati
ọwọ́-ẹran: ọkàn wọn yio si dabi ọgbà ti a
bomi rin; nwọn kì yio si kãnu mọ rara.
13 Nigbana ni wundia yio yọ̀ ninu ijó,
pẹlu ọdọmọkọnrin ati arugbo ṣọkan pọ̀:
nitori emi o sọ ọ̀fọ wọn di ayọ̀, emi o si tù
wọn ninu, emi o si mu wọn yọ̀ lẹhin ikãnu
wọn.
14 Emi o si fi sisanra tẹ ọkàn awọn
alufa lọrun, ore mi yio si tẹ awọn enia mi
lọrun, li Oluwa wi.
15 Bayi li Oluwa wi, Ni Rama li a gbọ
ohùnrere, ẹkún kikoro; Rakeli nsọkun fun
awọn ọmọ rẹ̀, kò gbipẹ nitori awọn ọmọ rẹ̀,
nitoripe nwon kò si.
16 Bayi li Oluwa wi; Dá ohùn rẹ duro
ninu ẹkun, ati oju rẹ ninu omije: nitori
iṣẹ rẹ ni ère, li Oluwa wi, nwọn o si pada
wá lati ilẹ ọta.
17 Ireti si wà ni igbẹhin rẹ, li Oluwa
wi, pe awọn ọmọ rẹ yio pada si agbegbe
wọn.
18 Lõtọ emi ti gbọ́ Efraimu npohùnrere
ara rẹ̀ bayi pe; Iwọ ti nà mi, emi si di
ninà, bi ọmọ-malu ti a kò kọ́; yi mi pada,
emi o si yipada; nitori iwọ li Oluwa Ọlọrun
mi.
19 Lõtọ lẹhin ti emi yipada, mo ronupi-
wada; ati lẹhin ti a kọ́ mi, mo lu ẹ̀gbẹ
mi: oju tì mi, lõtọ, ani mo dãmu, nitoripe
emi ru ẹ̀gan igba ewe mi.
20 Ọmọ ọ̀wọn ha ni Efraimu fun mi bi?
ọmọ inu-didùn ha ni?-nitori bi emi ti sọ̀rọ
si i to, sibẹ emi ranti rẹ̀, nitorina ni ọkàn
mi ṣe lù fun u; emi o ṣe iyọ́nu fun u nitõ-
tọ, li Oluwa wi.
21 Gbe àmi-ọ̀na soke, ṣe ọwọ̀n àmi: gbe
ọkàn rẹ si opopo ọ̀na, ani ọ̀na ti iwọ ti lọ:
tun yipada, iwọ wundia Israeli, tun yipada
si ilu rẹ wọnyi.
22 Iwọ o ti ṣina kiri pẹ to, iwọ apẹhinda
ọmọbirin? nitori Oluwa dá ohun titun ni
ilẹ na pe, Obirin kan yio yi ọkọnrin kan
ka.
23 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọ-
run Israeli wi, pe, Nwọn o si tun lò ède yi
ni ilẹ Juda ati ni ilu rẹ̀ wọnni, nigbati emi
o mu igbekun wọn pada, pe, Ki Oluwa ki o
bukun ọ, Ibugbe ododo, Oke ìwa-mimọ́!
24 Juda ati gbogbo ilu rẹ̀ yio ma jumọ
gbe inu rẹ̀, agbẹ, ati awọn ti mba agbo-
eran lọ kakiri,
25 Nitori emi tù ọkàn alãrẹ ninu, emi si
ti tẹ gbogbo ọkàn ikãnu lọrun.
26 Lori eyi ni mo ji, mo si wò; orun mi
si dùn mọ mi.
27 Wò o, ọjọ mbọ, li Oluwa wi, ti emi
o gbin ile Israeli ati Juda ni irugbin enia,
ati irugbin ẹran.
28 Yio si ṣe, pe gẹgẹ bi emi ti ṣọ́ wọn,
lati fà tu, ati lati fa lulẹ, ati lati wo lulẹ,
ati lati parun, ati lati pọnloju, bẹ̃ni emi o
ṣọ́ wọn, lati kọ́, ati lati gbìn, li Oluwa wi.
29 Li ọjọ wọnni, nwọn kì yio wi mọ pe,
Awọn baba ti jẹ eso ajara aipọn, ehín si ti
kan awọn ọmọ.
30 Ṣugbọn olukuluku ni yio kú nitori
aiṣedede rẹ̀, olukuluku ti o jẹ eso ajara-
aipọn ni ehín yio kan.
31 Wò o, ọjọ mbọ, li Oluwa wi, ti emi o
ba ile Israeli ati ile Juda dá majẹmu titun.
32 Kì iṣe bi majẹmu na ti emi ba baba
wọn dá li ọjọ na ti emi fà wọn lọwọ lati mu
wọn jade lati ilẹ Egipti: awọn ti nwọn dà
majẹmu mi, bi emi tilẹ jẹ alakoso wọn sibẹ,
li Oluwa wi;
33 Ṣugbọn eyi ni majẹmu ti emi o ba ile
Israeli da; Lẹhin ọjọ wọnni, li Oluwa wi,
emi o fi ofin mi si inu wọn, emi o si kọ ọ si
aiya wọn, emi o si jẹ Ọlọrun wọn, awọn o
si jẹ enia mi.
34 Nwọn kì yio si kọni mọ ẹnikini ẹni-
keji rẹ̀, ati ẹ̀gbọn, aburo rẹ̀ wipe, Mọ̀ Olu-
wa: nitoripe gbogbo nwọn ni yio mọ̀ mi,
lati ẹni-kekere wọn de ẹni-nla wọn, li Olu-
wa wi; nitori emi o dari aiṣedede wọn jì,
emi kì o si ranti ẹ̀ṣẹ wọn mọ.
35 Bayi li Oluwa wi ti o fi õrùn fun
imọlẹ li ọsan, ilana oṣupa ati irawọ fun
imọlẹ li oru, ti o rú okun soke tobẹ̃, ti riru
omi rẹ̀ nho; Oluwa awọn ọmọ-ogun li orukọ
rẹ̀:
36 Bi ilana wọnyi ba yẹ̀ kuro niwaju

Digitized by Google

mi, li Oluwa wi, njẹ iru-ọmọ Israeli pẹlu
yio dẹkun lati ma jẹ orilẹ-ède niwaju mi
lailai.
37 Bayi li Oluwa wi, Bi a ba le wọ̀n
ọrun loke, ti a si le wá ipilẹ aiye ri nisalẹ,
emi pẹlu yio ta iru-ọmọ Israeli nù nitori
gbogbo eyiti nwọn ti ṣe, li Oluwa wi.
38 Wò o, ọjọ mbọ, li Oluwa wi, ti a o
kọ́ ilu na fun Oluwa lati ile-iṣọ Hananeeli
de ẹnu-bode igun odi.
39 Okùn ìwọn yio si nà jade siwaju lẹba
rẹ̀ lori oke Garebi, yio si lọ yi Goati ka.
40 Ati gbogbo afonifoji okú, ati ti ẽru,
ati gbogbo oko titi de odò Kidroni, titi de
igun ẹnubode-ẹṣin niha ilà-õrun, ni yio jẹ
mimọ́ fun Oluwa; a kì yio fà a tu, bẹ̃ni a
kì yio si wó o lulẹ mọ lailai.

## ORI 32.

ỌRỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa
li ọdun kẹwa Sedekiah, ọba Juda,
eyiti o jẹ ọdun kejidilogun ti Nebukad-
nessari.
2 Nigbana ni ogun ọba Babeli ha Jeru-
salemu mọ: a si se Jeremiah woli mọ
agbala ile túbu, ti o wà ni ile ọba Juda.
3 Nitori Sedekiah, ọba Juda, ti se e
mọ, wipe, Ẽṣe ti iwọ sọtẹlẹ, ti o si wipe,
Bayi li Oluwa wi, wò o, emi o fi ilu yi le
ọwọ ọba Babeli, on o si ko o;
4 Ati Sedekiah, ọba Juda, kì yio bọ́ li
ọwọ awọn ara Kaldea, ṣugbọn a o fi i le ọwọ
ọba Babeli, lõtọ, yio si ba a sọ̀rọ li ojukoju,
oju rẹ̀ yio si ri oju rẹ̀.
5 On o si mu Sedekiah lọ si Babeli, nibẹ
ni yio si wà titi emi o fi bẹ̀ ẹ wò, li Oluwa
wi; bi ẹnyin tilẹ ba awọn ará Kaldea jà,
ẹnyin kì yio ṣe rere.
6 Jeremiah si wipe, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá
wipe,
7 Wò o, Hanameeli, ọmọ Ṣallumu,
ẹ̀gbọn rẹ, yio tọ̀ ọ wá, wipe, Iwọ rà oko mi
ti o wà ni Anatoti: nitori titọ́ irasilẹ jẹ
tirẹ lati rà a.
8 Hanameeli, ọmọ ẹ̀gbọn mi, si tọ̀ mi wá
li agbala ile túbu gẹgẹ bi ọ̀rọ Oluwa, o si
wi fun mi pe, Jọ̃, ra oko mi, ti o wà ni
Anatoti, ti o wà ni ilẹ Benjamini: nitori
titọ́ ogun rẹ̀ jẹ tirẹ, ati irasilẹ jẹ tirẹ; rà a
fun ara rẹ. Nigbana ni mo mọ̀ pe, eyi li
ọ̀rọ Oluwa.
9 Emi si rà oko na lọwọ Hanameeli,
ọmọ ẹ̀gbọn mi, ti o wà ni Anatoti, mo si
wọ̀n owo fun u, ṣekeli meje ati ìwọn fada-
ka mẹwa.
10 Mo si kọ ọ sinu iwe, mo si dì i, mo si
pè awọn ẹlẹri si i, mo si wọ̀n owo na ninu
òṣuwọn.
11 Mo si mu iwe rirà na eyiti a dí nipa
aṣẹ ati ilana, ati eyiti a ṣi silẹ.
12 Mo si fi iwe rirà na fun Baruki, ọmọ
Neriah, ọmọ Masseiah, li oju Hanameeli,
ọmọ ẹ̀gbọn mi, ati niwaju awọn ẹlẹri ti o
kọ orukọ wọn si iwe rirà na, niwaju gbo-
gbo ọkọnrin Juda ti o joko ni àgbala ile
túbu.
13 Mo si paṣẹ fun Baruki li oju wọn
wipe,
14 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlo-
run Israeli wipe, Mu iwe wọnyi, iwe rirà
yi, ti a dí, ati iwe yi ti a ṣi silẹ; ki o si fi
wọn sinu ikoko, ki nwọn ki o le wà li ọjọ
pupọ.
15 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun,
Ọlọrun Israeli, wipe, A o tun rà ile ati oko
ati ọgba-ajara ni ilẹ yi.
16 Mo si gbadura si Oluwa lẹhin igbati
mo ti fi iwe rirà na fun Baruki, ọmọ Ne-
riah, wipe,
17 A! Oluwa Ọlọrun! wò o, iwọ ti o
da ọrun on aiye nipa agbara nla rẹ ati ninà
apa rẹ: kò si ohun-kohun ti o ṣoro fun ọ.
18 Iwọ ṣe ãnu fun ẹgbẹgbẹrun, o si san
aiṣedede awọn baba si aiya awọn ọmọ lẹhin
wọn: Ọlọrun titobi, Alagbara! Oluwa
awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀.
19 Titobi ni igbimọ, ati alagbara ni iṣe;
oju rẹ ṣí si gbogbo ọ̀na awọn ọmọ enia: lati
fi fun olukuluku gẹgẹ bi ọ̀na rẹ̀ ati gẹgẹ bi
eso iṣe rẹ̀:
20 Ẹniti o gbe àmi ati iṣẹ-iyanu kalẹ ni
Egipti, titi di oni yi, ati lara Israeli, ati
lara enia miran: ti iwọ si ti ṣe orukọ fun
ara rẹ, gẹgẹ bi o ti ri li oni yi.
21 Ti o si fi àmi ati iṣẹ-iyanu, ati ọwọ
agbara, ati ninà apa ati ẹ̀ru nla mu Israeli
enia rẹ jade ni ilẹ Egipti.
22 Ti iwọ si ti fun wọn ni ilẹ yi, eyiti
iwọ bura fun awọn baba wọn lati fi fun
wọn, ilẹ ti nṣàn fun wara ati oyin;
23 Nwọn si wá, nwọn si ni i; ṣugbọn
nwọn kò gbà ohùn rẹ gbọ́, bẹ̃ni nwọn kò
rìn ninu ofin rẹ, nwọn kò ṣe gbogbo eyiti
iwọ paṣẹ fun wọn lati ṣe: iwọ si pè gbogbo
ibi yi wá sori wọn:
24 Wo o! odi ọta! nwọn summọ ilu
lati kó o; a si fi ilu le ọwọ awọn ara Kal-
dea, ti mba a jà, niwaju idà, ati ìyan, àja-
kalẹ-àrun: ati ohun ti iwọ ti sọ, ṣẹ; si wò
o, iwọ ri i.
25 Ṣugbọn iwọ ti sọ fun mi, Oluwa
Ọlọrun! pe, Iwọ fi owo rà oko na fun ara

Digitized by Google

rẹ, ki o si pe awọn ẹlẹri; sibẹ, a fi ilu le
ọwọ awọn ara Kildea.
26 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ Jeremiah
wà, wipe,
27 Wò o, emi li Oluwa, Ọlọrun gbogbo
ẹran-ara: ohun kan ha wà ti o ṣoro fun mi
bi?
28 Nitorina, bayi li Oluwa wi, Wò o,
emi o fi ilu yi le ọwọ awọn ara Kaldea, ani
le ọwọ Nebukadnessari, ọba Babeli, on o si
kó o:
29 Ati awọn ara Kaldea, ti mba ilu yi
jà, nwọn o wá, nwọn o si tẹ iná bọ̀ ilu yi,
nwọn o si kun u, ati ile, lori orule eyiti
nwọn ti nrubọ turari si Baali, ti nwọn si ti
ndà ẹbọ ohun mimu fun ọlọrun miran,
lati mu mi binu.
30 Nitori awọn ọmọ Israeli ati awọn
ọmọ Juda ti ṣe kiki ibi niwaju mi lati igba
ewe wọn wá: nitori awọn ọmọ Israeli ti fi
kiki iṣẹ ọwọ wọn mu mi binu, li Oluwa wi.
31 Nitori ilu yi ti jẹ ohun ibinu ati
irunu fun mi lati ọjọ ti nwọn ti kọ ọ wá
titi di oni yi; tobẽ ti emi o mu u kuro ni-
waju mi.
32 Nitori gbogbo ibi awọn ọmọ Israeli,
ati awọn ọmọ Juda, ti nwọn ti ṣe lati mu
mi binu, awọn, awọn ọba wọn, ijoye wọn,
alufa wọn, ati woli wọn, ati awọn ọkọnrin
Juda, ati awọn olugbe Jerusalemu.
33 Nwọn si ti yi ẹhin wọn pada si mi,
kì isi ṣe oju: emi kọ́ wọn, mo ndide ni
kutukutu lati kọ́ wọn, sibẹ nwọn kò feti-
silẹ lati gbà ẹkọ.
34 Nwọn si gbe ohun irira wọn ka inu
ile na, ti a fi orukọ mi pè, lati sọ ọ di
aimọ́.
35 Nwọn si kọ́ ibi giga Baali, ti o wà ni
afonifoji ọmọ Hinnomu, lati fi awọn ọmọ-
kọnrin wọn ati awọn ọmọbirin wọn fun
Moleki; ti emi kò paṣẹ fun wọn, bẽni kò
wá si ọkàn mi, pe ki nwọn ki o mã ṣe
ohun irira yi, lati mu Juda ṣẹ̀.
36 Njẹ nisisiyi, bayi li Oluwa Ọlọrun
Israeli wi, niti ilu yi, sipa eyiti ẹnyin
wipe, A o fi le ọwọ ọba Babeli, nipa idà,
ati nipa ìyan, ati nipa ajakalẹ-arun.
37 Wò o, emi o kó wọn jọ lati gbogbo
ilẹ jade, nibiti emi ti le wọn si ninu ibinu
mi, ati ninu irunu mi, ati ninu ikannu
nla; emi o si jẹ ki nwọn ki o mã gbe
lailewu:
38 Nwọn o si jẹ enia mi, emi o si jẹ
Ọlọrun wọn.
39 Emi o si fun wọn li ọkàn kan, ati
ọ̀na kan, ki nwọn ki o le bẹ̀ru mi li ọjọ
gbogbo, fun rere wọn, ati ti awọn ọmọ wọn
lẹhin wọn:
40 Emi o si ba wọn dá majẹmu aiyera-
iye, pe emi kì o yipada lẹhin wọn lati ṣe
wọn ni rere, emi o fi ibẹ̀ru mi si ọkàn wọn,
ti nwọn kì o lọ kuro lọdọ mi.
41 Lõtọ, emi o yọ̀ lori wọn lati ṣe wọn
ni rere, emi o si gbìn wọn si ilẹ yi li otitọ
tinutinu mi ati tọkàntọkàn mi.
42 Nitori bayi li Oluwa wi; Gẹgẹ bi emi
ti mu gbogbo ibi nla yi wá sori awọn enia
yi, bẽni emi o mu gbogbo rere ti emi ti sọ
nipa ti wọn wá sori wọn.
43 Enia o si rà oko ni ilẹ yi, sipa eyi ti
ẹnyin wipe, Ahoro ni laisi enia, laisi ẹran,
a fi le ọwọ awọn ara Kaldea.
44 Enia yio fi owo rà oko, nwọn o kọ ọ
sinu iwe, nwọn o si dí i, nwọn o si pe awọn
ẹlẹri ni ilẹ Benjamini, ati ni ibi wọnni yi
Jerusalemu ka, ati ni ilu Juda, ati ni ilu
ọwọ́-oke na, ati ni ilu afonifọji, ati ni ilu
iha gusu; nitori emi o mu igbekun wọn
pada wá, li Oluwa wi.

## ORI 33.

ÒRỌ Oluwa si tọ̀ Jeremiah wá lẹ̃keji, ni-
gbati a si se e mọ ninu agbala ile túbu,
wipe,
2 Bayi li Oluwa wi, ẹniti o ṣe e, Oluwa,
ti o pinnu rẹ̀, lati fi idi rẹ̀ mulẹ; Oluwa li
orukọ rẹ̀;
3 Képe mi, emi o si da ọ lohùn, emi o si
fi ohun nla ati alagbara han ọ ti iwọ kò
mọ̀.
4 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli
wi, niti ile ilu yi, ati niti ile awọn ọba
Juda ti a wó lulẹ ati nitori odi ati nitori
idà;
5 Nwọn wá lati ba awọn ara Kaldea jà,
ṣugbọn lati fi okú enia kún wọn, awọn ẹniti
Emi pa ninu ibinu mi ati ninu irunu mi,
ati nitori gbogbo buburu wọnni, nitori
eyiti emi ti pa oju mi mọ fun ilu yi.
6 Wò o, emi o fi ọjá ati õgùn imularada
dì i, emi o si wò wọn san, emi o si fi ọ̀pọ-
lọpọ alafia ati otitọ hàn fun wọn.
7 Emi o si mu igbèkun Juda ati igbèkun
Israeli pada wá, emi o si gbe wọn ró gẹgẹ
bi ti iṣaju.
8 Emi o si wẹ̀ wọn nù kuro ninu gbogbo
aiṣedede wọn, nipa eyiti nwọn ti ṣẹ̀ si mi;
emi o si dari gbogbo aiṣedede wọn jì nipa
eyiti nwọn ti ṣẹ̀, ati nipa eyi ti nwọn ti ṣe
irekọja si mi.
9 Ilu na yio si jẹ orukọ ayọ̀ fun mi,
iyìn ati ọlá niwaju gbogbo orilẹ-ède ilẹ

Digitized by Google

aiye, ti nwọn gbọ́ gbogbo rere ti emi ṣe fun
wọn: nwọn o si bẹ̀ru, nwọn o si warìri,
nitori gbogbo ore ati nitori gbogbo alafia ti
emi ṣe fun u.
10 Bayi li Oluwa wi; A o si tun gbọ́ ni
ibi yi ti ẹnyin wipe, O dahoro, laini enia
ati laini ẹran, ani ni ilu Juda, ati ni ilu
Jerusalemu, ti o dahoro, laini enia, ati
laini olugbe, ati laini ẹran.
11 Ohùn ayọ̀, ati ohùn inu-didùn, ohùn
ọkọ-iyawo, ati ohùn iyawo, ohùn awọn ti o
wipe, Ẹ fi ọpẹ fun Oluwa awọn ọmọ-ogun:
nitori ti o ṣeun, nitoriti ãnu rẹ̀ duro lailai:
ati ti awọn ti o mu ẹbọ-ọpẹ́ wá si ile Oluwa.
Nitoriti emi o mu igbèkun ilẹ na pada wá
gẹgẹ bi atetekọṣe, li Oluwa wi.
12 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi pe;
Papa-oko awọn oluṣọ-agutan yio tun wà, ti
nwọn mu ẹran-ọsin dubulẹ ni ibi yi, ti o
dahoro, laini enia ati laini ẹran, ati ni
gbogbo ilu rẹ̀!
13 Ninu ilu oke wọnni, ninu ilu afoni-
foji, ati ninu ilu iha gusu, ati ni ilẹ Benja-
mini, ati ni ibi wọnni yi Jerusalemu ka,
ati ni ilu Juda ni agbo agutan yio ma kọja
labẹ ọwọ ẹniti nkà wọn, li Oluwa wi.
14 Wò o, ọjọ mbọ, li Oluwa wi, ti emi o
mu ohun rere na, ti emi ti leri fun ile
Israeli ati fun ile Juda, ṣẹ.
15 Li ọjọ wọnni, ati li akoko na, emi o
jẹ ki Ẹka ododo ki o hù soke fun Dafidi;
ẹniti yio si ṣe idajọ ati ododo ni ilẹ na.
16 Li ọjọ wọnni li a o gbà Juda la, Jeru-
salemu yio si ma gbe li ailewu: orukọ yi
li a o ma pè e: OLUWA ODODO WA.
17 Nitori bayi li Oluwa wi; A kì o fẹ
ọkọnrin kan kù lọdọ Dafidi lati joko lori
itẹ́ ile Israeli lailai.
18 Bẹ̃ni awọn alufa, awọn ọmọ Lefi, kì
yio fẹ ọkọnrin kan kù niwaju mi lati ru ẹbọ
sisun, ati lati dana ọrẹ ohun jijẹ, ati lati
ṣe irubọ lojojumọ.
19 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ Jeremiah wá, wipe,
20 Bayi li Oluwa wi; Bi ẹnyin ba le bà
majẹmu mi ti ọsan jẹ, ati majẹmu mi ti
oru, tí ọsan ati oru kò le si li akoko wọn;
21 Nigbana ni majẹmu mi pẹlu Dafidi,
iranṣẹ mi le bajẹ, pe ki on ki o má le ni
ọmọ lati joko lori itẹ rẹ̀; ati pẹlu awọn
ọmọ Lefi, awọn alufa, awọn iranṣẹ mi.
22 Gẹgẹ bi a kò ti le ka iye ogun-ọrun,
tabi ki a le wọ̀n iyanrin eti okun: bẹ̃ni
emi o sọ iru-ọmọ Dafidi iranṣẹ mi di pupọ,
ati awọn ọmọ Lefi, ti nṣe iranṣẹ fun mi.
23 Ọ̀rọ Oluwa si tọ Jeremiah wà, wipe,
24 Iwọ kò ha ro eyi ti awọn enia yi ti
sọ wipe, Idile meji ti Oluwa ti yàn, o ti kọ̀
wọn silẹ̀? nitorina ni nwọn ti ṣe kẹgan
awọn enia mi, pe nwọn kì o le jẹ orilẹ-ède
kan mọ li oju wọn.
25 Bayi li Oluwa wi, Bi emi kò ba paṣẹ
majẹmu mi ti ọsan ati ti oru, pẹlu ilana
ọrun ati aiye,
26 Nigbana ni emi iba ta iru-ọmọ Ja-
kobu nù, ati Dafidi, iranṣẹ mi, ti emi kì o
fi mu ninu iru-ọmọ rẹ̀ lati ṣe alakoso lori
iru-ọmọ Abrahamu, Isaaki, ati Jakobu:
nitori emi o mu ki igbekun wọn ki o pada
bọ̀, emi o si ṣãnu fun wọn.

## ORI 34.

ỌRỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa,
ni wakati ti Nebukadnessari, ọba Ba-
beli, ati gbogbo ogun rẹ̀, ati gbogbo ijọba
ilẹ-ijọba ọwọ rẹ̀, ati gbogbo awọn orilẹ-ède,
mba Jerusalemu ati gbogbo ilu rẹ̀ ja, wipe:
2 Bayi li Oluwa, Ọlọrun Israeli, wi:
Lọ, ki o si sọ fun Sedekiah, ọba Juda, ki
o si wi fun u pe, Bayi li Oluwa wi; Wò o,
emi o fi ilu yi le ọwọ ọba Babeli, on o si fi
iná kun u:
3 Iwọ kì o si le sala kuro lọwọ rẹ̀,
ṣugbọn ni mimú a o mu ọ, a o si fi ọ le e
lọwọ; oju rẹ yio si ri oju ọba Babeli, on o
si ba ọ sọ̀rọ lojukoju, iwọ o si lọ si Babeli.
4 Sibẹ, gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, iwọ Sedekiah,
ọba Juda: Bayi li Oluwa wi niti rẹ, Iwọ
kì yio ti ipa idà kú.
5 Iwọ o kú li alafia: ati bi ijona-isinkú
awọn baba rẹ, awọn ọba igbãni ti o wà ṣaju
rẹ, bẹ̃ni nwọn o si ṣe ijona-isinkú fun ọ,
nwọn o si pohunrere rẹ, pe, Yẽ oluwa!
nitori eyi li ọ̀rọ ti emi ti sọ, li Oluwa wi.
6 Jeremiah woli, si sọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi
fun Sedekiah, ọba Juda ni Jerusalemu.
7 Ni wakati na ogun ọba Babeli mba
Jerusalemu jà, ati gbogbo ilu Juda ti o kù,
Lakiṣi, ati Aseka: wọnyi li o kù ninu ilu
Juda, nitori nwọn jẹ ilu olodi.
8 Ọ̀rọ ti o tọ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa
lẹhin ti Sedekiah, ọba, ti ba gbogbo enia
ti o wà ni Jerusalemu dá majẹmu, lati kede
omnira fun wọn.
9 Pe, ki olukuluku enia le jẹ ki iranṣẹ-
kọnrin rẹ̀, ati olukuluku enia, iranṣẹbirin
rẹ̀, ti iṣe ọkọnrin Heberu tabi obirin Hebe-
ru, lọ lọfẹ; ki ẹnikẹni ki o má mu ara
Juda, arakọnrin rẹ̀, sin.
10 Njẹ nigbati gbogbo awọn ijoye, ati
gbogbo enia, ti nwọn dá majẹmu yi, gbọ́
pe ki olukuluku ki o jẹ ki iranṣẹkọnrin rẹ̀,
ati olukuluku, iranṣẹbirin rẹ̀, lọ lọfẹ, ki

Digitized by Google

ẹnikan má mu wọn sin wọn mọ, nwọn gbọ́,
nwọn si jọ̀ wọn lọwọ.
11 Ṣugbọn lẹhin na nwọn yi ọkàn pada,
nwọn si mu ki awọn iranṣẹkọnrin ati awọn
iranṣẹbirin, awọn ẹniti nwọn ti jẹ ki o lọ
lọfẹ, ki o pada, nwọn si mu wọn sin bi
iranṣẹkọnrin ati bi iranṣẹbirin.
12 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ Jeremiah
wá lati ọdọ Oluwa, wipe,
13 Bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli, wi,
pe ; Emi ba awọn baba nyin dá majẹmu li
ọjọ ti emi mu wọn jade lati ilẹ Egipti,
kuro ninu oko-ẹrú, wipe,
14 Li opin ọdọ̀dun meje ki olukuluku
enia jẹ ki arakọnrin rẹ̀ ki o lọ, ani ara
Heberu ti o ta ara rẹ̀ fun ọ ; yio si sin ọ li
ọdun mẹfa, nigbana ni iwọ o jẹ ki o lọ lọfẹ
lọdọ rẹ : ṣugbọn awọn baba nyin kò gbọ́
temi, bẽni nwọn kò tẹti wọn silẹ.
15 Ẹnyin si yi ọkàn pada loni, ẹ si ti ṣe
eyi ti o tọ li oju mi, ni kikede omnira,
ẹnikini fun ẹnikeji rẹ̀ ; ẹnyin si ti dá majẹ-
mu niwaju mi ni ile ti a fi orukọ mi pè :
16 Ṣugbọn ẹnyin yipada, ẹ si sọ orukọ
mi di ẽri, olukuluku enia si mu ki iranṣẹ-
kọnrin rẹ̀, ati olukuluku enia iranṣẹbirin
rẹ̀, ti on ti sọ di omnira ni ifẹ wọn, ki o
pada, ẹnyin si mu wọn sin lati jẹ iranṣẹ-
kọnrin ati iranṣẹbirin, fun nyin.
17 Nitorina bayi li Oluwa wi, Ẹnyin kò
feti si mi, ni kikede omnira, ẹgbọn fun
aburo rẹ̀, ati ẹnikini fun ẹnikeji rẹ̀ : wò o,
emi o kede omnira fun nyin, li Oluwa wi,
si idà, si ajakalẹ-àrun, ati si ìyan, emi o si
fi nyin fun iwọsi ni gbogbo ijọba ilẹ aiye.
18 Emi o si ṣe awọn ọkọnrin na, ti o ti
ré majẹmu mi kọja, ti kò ṣe ọ̀rọ majẹmu ti
nwọn ti dá niwaju mi, bi ẹgbọrọ malu ti
nwọn ti ke meji, ti nwọn si kọja lãrin ipin
mejeji rẹ̀,
19 Awọn ijoye Juda, ati awọn ijoye
Jerusalemu, awọn ìwẹfa, ati awọn alufa,
ati gbogbo enia ilẹ na, ti o kọja lãrin ipin
mejeji ẹgbọrọ malu na ;
20 Emi o fi wọn le ọwọ awọn ọta wọn,
ati le ọwọ awọn ti nwá ẹmi wọn : okú wọn
yio si jẹ onjẹ fun awọn ẹiyẹ oju-ọrun, ati
fun awọn ẹranko igbẹ.
21 Ati Sedekiah, ọba Juda, ati awọn
ijoye rẹ̀ li emi o fi le ọwọ awọn ọta wọn,
ati le ọwọ awọn ti nwá ẹmi wọn, ati le
ọwọ ogun ọba Babeli, ti o ṣi lọ kuro lọdọ
nyin.
22 Wò o, emi o paṣẹ, li Oluwa wi : emi
o si mu wọn pada si ilu yi ; nwọn o si ba
a jà, nwọn o si kó o, nwọn o si fi iná kún
u : emi o si ṣe ilu Juda li ahoro laini
olugbe.

## ORI 35.

ỌRỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa
li ọjọ Jehoiakimu, ọmọ Josiah, ọba
Juda, wipe :
2 Lọ si ile awọn ọmọ Rekabu, ki o si ba
wọn sọ̀rọ, ki o si mu wọn wá si ile Oluwa,
si ọkan ninu iyara wọnni, ki o si fun wọn
li ọti-waini mu.
3 Nigbana ni mo mu Jaasaniah, ọmọ
Jeremiah, ọmọ Habasiniah, ati awọn ara-
kọnrin rẹ̀, ati gbogbo awọn ọmọ rẹ̀, ati
gbogbo ile awọn ọmọ Rekabu ;
4 Mo si mu wọn wá si ile Oluwa, sinu
iyara awọn ọmọ Hanani, ọmọ Igdaliah,
enia Ọlọrun, ti o wà lẹba iyara awọn ijoye,
ti o wà li oke iyara Maaseiah, ọmọ Sallu-
mu, olutọju ẹnu-ọ̀na,
5 Mo si gbe ìkoko ti o kún fun ọti-
waini pẹlu ago, ka iwaju awọn ọmọ ile
Rekabu, mo si wi fun wọn pe : Ẹ mu ọti-
waini.
6 Ṣugbọn nwọn wipe, Awa kì yio mu
ọti-waini, nitori Jonadabu, ọmọ Rekabu,
baba wa, paṣẹ fun wa pe : Ẹnyin kò gbọdọ
mu ọti-waini, ẹnyin ati awọn ọmọ nyin
lailai.
7 Bẽni ẹnyin kò gbọdọ kọ́ ile, tabi ki ẹ
fun irugbin, tabi ki ẹ gbin ọgba-àjara, bẽni
ẹnyin kò gbọdọ ni ; ṣugbọn ni gbogbo ọjọ
nyin li ẹnyin o ma gbe inu agọ ; ki ẹnyin
ki o le wà li ọjọ pupọ ni ilẹ na nibiti ẹnyin
nṣe atipo.
8 Bayi li awa gbà ohùn Jonadabu, ọmọ
Rekabu, baba wa gbọ́ ninu gbogbo eyiti o
palaṣẹ fun wa, ki a má mu ọti-waini ni
gbogbo ọjọ wa, awa, awọn aya wa, awọn
ọmọkọnrin wa, ati awọn ọmọbirin wa ;
9 Ati ki a má kọ ile lati gbe ; bẽni awa
kò ni ọgba-ajara, tabi oko, tabi ohun ọgbin.
10 Ṣugbọn awa ngbe inu agọ, a si gbọ-
ran, a si ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti Jonadabu,
baba wa, palaṣe fun wa.
11 O si ṣe, nigbati Nebukadnessari, ọba
Babeli, goke wá si ilẹ na, ni awa wipe, Ẹ
wá, ẹ jẹ ki a lọ si Jerusalemu, nitori ibẹ̀ru
ogun awọn ara Kaldea, ati nitori ibẹ̀ru
ogun awọn ara Siria : bẽni awa ngbe Jeru-
salemu.
12 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Jeremiah
wá wipe :
13 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun
Israeli, wi pe, Lọ, ki o si sọ fun awọn ọkọn-
rin Juda, ati awọn olugbe Jerusalemu pe,

Digitized by Google

Ẹnyin kì yio ha gbà ẹkọ lati feti si ọ̀rọ mi? li Oluwa wi.

14 Ọ̀rọ Jonadabu, ọmọ Rekabu, ti o pa laṣẹ fun awọn ọmọ rẹ̀, pe, ki nwọn ki o má mu ọti-waini, ni a mu ṣẹ; nwọn kò si mu ọti-waini titi di oni yi. Nitoriti nwọn gbọ́ ofin baba wọn, emi si ti nsọ̀rọ fun nyin, emi dide ni kutukutu, emi nsọ: ṣugbọn ẹnyin kò fetisi ti emi.

15 Emi si ti rán gbogbo awọn iranṣẹ mi, awọn woli, si nyin pẹlu, emi dide ni kutukutu, mo ran wọn wipe, Ẹ yipada nisisiyi, olukuluku kuro ni ọ̀na buburu rẹ̀, ki ẹ si tun iṣe nyin ṣe rere, ki ẹ máṣe tọ̀ awọn ọlọrun miran lẹhin lati sin wọn, ẹnyin o si ma gbe ilẹ na ti mo ti fi fun nyin, ati fun awọn baba nyin; ṣugbọn ẹnyin kò tẹ eti nyin, bẽni ẹnyin kò si gbọ́ temi.

16 Lõtọ awọn ọmọ Jonadabu, ọmọ Rekabu, pa ofin baba wọn mọ, ti o pa laṣẹ fun wọn; ṣugbọn awọn enia yi kò gbọ́ ti emi:

17 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun Israeli wi pe, Wò o, emi o mu wá sori Juda, ati sori gbogbo olugbe Jerusalemu, gbogbo ibi ti emi ti sọ si wọn; nitori ti emi ti ba wọn sọ̀rọ, nwọn kò si gbọ́; mo si ti pè wọn, nwọn kò si dahùn.

18 Jeremiah si wi fun ile awọn ọmọ Rekabu pe, Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli wi pe, Nitori ti ẹnyin gbà ofin Jonadabu, baba nyin gbọ́, ti ẹnyin si pa gbogbo ilana rẹ̀ mọ, ti ẹ si ṣe gẹgẹ bi eyi ti o ti palaṣẹ fun nyin:

19 Nitorina bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi, pe, Jonadabu, ọmọ Rekabu kì yio fẹ ọkọnrin kan kù lati duro niwaju mi lailai.

## ORI 36.

O SI ṣe li ọdun kẹrin Jehoiakimu, ọmọ Josiah ọba Juda, li ọ̀rọ yi tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa wá, wipe,

2 Mu iwe-kiká fun ara rẹ, ki o si kọ sinu rẹ̀, gbogbo ọ̀rọ ti emi ti sọ si Israeli, ati si Juda, ati si gbogbo orilẹ-ède, lati ọjọ ti mo ti sọ fun ọ, lati ọjọ Josiah titi di oni yi.

3 O le jẹ pe ile Juda yio gbọ́ gbogbo ibi ti mo pinnu lati ṣe si wọn; ki nwọn ki o le yipada, olukuluku kuro li ọ̀na buburu rẹ̀; ki emi ki o dari aiṣedede wọn ati ẹ̀ṣẹ wọn ji wọn.

4 Nigbana ni Jeremiah pè Baruku, ọmọ Neriah; Baruku si kọ lati ẹnu Jeremiah gbogbo ọ̀rọ Oluwa ti o ti sọ fun u, sori iwe-kiká na.

5 Jeremiah si paṣẹ fun Baruku pe, a se mi mọ: emi kò le lọ si ile Oluwa:

6 Nitorina iwọ lọ, ki o si kà ninu iwe-kika na, ti iwọ kọ lati ẹnu mi wá, ọ̀rọ Oluwa li eti awọn enia ni ile Oluwa li ọjọ ãwẹ: ati pẹlu, iwọ o si kà a li eti gbogbo Juda, ti nwọn jade wá lati ilu wọn.

7 O le jẹ pe, ẹ̀bẹ wọn yio wá siwaju Oluwa, nwọn o si yipada, olukuluku kuro li ọ̀na buburu rẹ̀: nitoripe nla ni ibinu ati irunu ti Oluwa ti sọ si awọn enia yi.

8 Baruku, ọmọ Neriah, si ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti Jeremiah, woli, ti palaṣẹ fun u, lati ka ọ̀rọ Oluwa lati inu iwe ni ile Oluwa.

9 O si ṣe li ọdun karun Jehoiakimu, ọmọ Josiah, ọba Juda, li oṣu kẹsan ni nwon kede ãwẹ niwaju Oluwa, fun gbogbo enia ni Jerusalemu: ati fun gbogbo awọn enia ti o wá lati ilu Juda, si Jerusalemu.

10 Baruku si ka ọ̀rọ Jeremiah lati inu iwe ni ile Oluwa, ni iyara Gemariah, ọmọ Ṣafani, akọwe, ni àgbala oke, nibi ilẹkun ẹnu-ọ̀na titun ile Oluwa li eti gbogbo enia.

11 Nigbati Mikaiah, ọmọ Gemariah, ọmọ Ṣafani, gbọ́ gbogbo ọ̀rọ Oluwa lati inu iwe na wá,

12 O si sọkalẹ lọ si ile ọba, sinu iyara akọwe, si wò o, gbogbo awọn ijoye joko nibẹ, Eliṣama, akọwe, ati Delaiah, ọmọ Semaiah, ati Elnatani, ọmọ Akbori, ati Gemariah, ọmọ Ṣafani, ati Sedekiah, ọmọ Hananiah, ati gbogbo awọn ijoye.

13 Nigbana ni Mikaiah sọ gbogbo ọ̀rọ wọnni ti o ti gbọ́, fun wọn, nigbati Baruku kà lati inu iwe na li eti awọn enia.

14 Nigbana ni gbogbo awọn ijoye rán Jehudu, ọmọ Netaniah, ọmọ Ṣelemiah, ọmọ Kuṣi, si Baruku wipe, Mu iwe-kiká na li ọwọ rẹ, lati inu eyiti iwọ kà li eti awọn enia, ki o si wá. Nigbana ni Baruku, ọmọ Neriah, mu iwe-kiká na li ọwọ rẹ̀, o si wá si ọdọ wọn.

15 Nwọn si wi fun u pe, Joko nisisiyi, ki o si kà a li eti wa. Baruku si kà a li eti wọn.

16 Njẹ, o si ṣe, nigbati nwọn gbọ́ gbogbo ọ̀rọ na, nwọn wariri, ẹnikini si ẹnikeji rẹ̀, nwọn si wi fun Baruku pe, Awa kò le ṣe aisọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi fun ọba.

17 Nwọn si bi Baruku wipe, Sọ fun wa nisisiyi, bawo ni iwọ ṣe kọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi lati ẹnu rẹ̀?

18 Baruku si da wọn lohùn pe; Lati

Digitized by Google

ẹnu rẹ̀ li o si sọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi fun mi,
emi si fi tadawa kọ wọn sinu iwe na.
19 Nigbana ni awọn ijoye sọ fun Ba-
ruku pe, Lọ, fi ara rẹ pamọ, iwọ ati Jere-
miah; má si jẹ ki ẹnikan mọ̀ ibi ti ẹnyin
wà.
20 Nwọn si wọle tọ̀ ọba lọ ninu àgbala,
ṣugbọn nwọn fi iwe-kiká na pamọ si iyara
Eliṣama, akọwe, nwọn si sọ gbogbo ọ̀rọ na
li eti ọba.
21 Ọba si rán Jehudu lati lọ mu iwe-
kiká na wá: on si mu u jade lati inu iyara
Eliṣama, akọwe. Jehudu si kà a li eti ọba,
ati li eti gbogbo awọn ijoye, ti o duro tì
ọba.
22 Ọba si ngbe ile igba-otutu li oṣu
kẹsan: ina si njo niwaju rẹ̀ ninu idana.
23 O si ṣe, nigbati Jehudu ti kà ewe
mẹta tabi mẹrin, ọba fi ọbẹ ke iwe na, o
si sọ ọ sinu iná ti o wà ninu idaná, titi
gbogbo iwe-kiká na fi joná ninu iná ti o
wà lori idaná.
24 Sibẹ nwọn kò warìri, nwọn kò si fa
aṣọ wọn ya, ani ọba, ati gbogbo awọn ọmọ-
ọdọ rẹ̀ ti o gbọ́ gbogbo ọ̀rọ wọnyi.
25 Ṣugbọn Elnatani ati Delaiah ati Ge-
mariah bẹbẹ lọdọ ọba ki o máṣe fi iwe-kiká
na joná, kò si fẹ igbọ́ ti wọn.
26 Ṣugbọn ọba paṣẹ fun Jerameeli, ọmọ
Hameleki, ati Seraiah, ọmọ Asraeli, ati
Ṣelemiah, ọmọ Abdeeli, lati mu Baruku
akọwe, ati Jeremiah woli: ṣugbọn Oluwa
fi wọn pamọ.
27 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Jeremiah
wá, lẹhin ti ọba ti fi iwe-kiká na ati ọ̀rọ
ti Baruku kọ lati ẹnu Jeremiah wá joná,
wipe,
28 Tun mu iwe-kiká miran, ki o si kọ
gbogbo ọ̀rọ iṣaju sinu rẹ̀ ti o wà ninu iwe-
kiká ekini, ti Jehoiakimu, ọba Juda, ti fi
joná.
29 Iwọ o si sọ niti Jehoiakimu, ọba
Juda, pe, Bayi li Oluwa wi; Iwọ ti fi iwẹ-
kiká yi joná o si wipe, Ẽṣe ti iwọ fi kọwe
sinu rẹ̀, pe: Lõtọ ọba Babeli yio wá yio si
pa ilẹ yi run, yio si pa enia ati ẹran run
kuro ninu rẹ̀?
30 Nitorina bayi li Oluwa wi niti Jeho-
iakimu, ọba Juda, pe, On kì yio ni ẹniti
yio joko lori itẹ Dafidi: a o si sọ okú
rẹ̀ nù fun oru li ọsan, ati fun otutu li
oru.
31 Emi o si jẹ on, ati iru-ọmọ rẹ̀, ati
awọn iranṣẹ rẹ̀ niya, nitori aiṣedede wọn;
emi o si mu wá sori wọn, ati sori awọn
olugbe Jerusalemu, ati sori awọn ọkọnrin
Juda, gbogbo ibi ti emi ti sọ si wọn, ṣugbọn
nwọn kò gbọ́.
32 Nigbana ni Jeremiah mu iwe-kiká
miran, o si fi i fun Baruku, akọwe, ọmọ
Neriah; ẹniti o kọwe sinu rẹ̀ lati ẹnu Jere-
miah gbogbo ọ̀rọ iwe ti Jehoiakimu, ọba
Juda ti sun ninu iná: a si fi ọ̀rọ pupọ bi
iru eyi kún ọ̀rọ iwe na pẹlu.

## ORI 37.

SEDEKIAH, ọmọ Josiah si jọba ni ipo
Koniah, ọmọ Jehoiakimu, ẹniti Ne-
bukadnessari, ọba Babeli, fi jẹ ọba ni ilẹ
Juda.
2 Ṣugbọn ati on, ati awọn iranṣẹ rẹ̀, ati
awọn enia ilẹ na, kò fetisi ọ̀rọ Oluwa, ti o
sọ nipa Jeremiah, woli.
3 Sedekiah, ọba si ran Jehukali, ọmọ
Ṣelemiah, ati Ṣefaniah, ọmọ Maaseiah, alu-
fa, si Jeremiah woli, wipe: Njẹ, bẹbẹ lọdọ
Oluwa Ọlọrun wa fun wa.
4 Jeremiah si nwọle o si njade lãrin
awọn enia: nitori nwọn kò ti ifi i sinu
tubu.
5 Ogun Farao si jade lati Egipti wá:
nigbati awọn ara Kaldea ti o dótì Jeru-
salemu si gbọ́ iró wọn, nwọn lọ kuro ni
Jerusalemu.
6 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Jeremiah,
woli wá, wipe,
7 Bayi li Oluwa, Ọlọrun Israeli wi pe,
Bayi li ẹnyin o sọ fun ọba Juda, ti o rán
nyin si mi, lati bere lọwọ mi: Wò o, ogun
Farao ti o jade lati ràn nyin lọwọ, yio pada
si ilẹ rẹ̀, ani Egipti.
8 Awọn ara Kaldea yio si tun wá, nwọn
o si ba ilu yi jà, nwọn o kó o, nwọn o si fi
iná kún u.
9 Bayi li Oluwa wi; Ẹ máṣe tan ọkán
nyin jẹ, wipe, Ni lilọ awọn ara Kaldea yio
lọ kuro lọdọ wa: nitoriti nwọn kì yio lọ.
10 Nitori bi o tilẹ jẹ pe, ẹnyin lu gbogbo
ogun awọn ara Kaldea ti mba nyin jà bolẹ,
ti o si jẹ pe awọn ọkọnrin ti o gbọgbẹ li o
kù ninu wọn: sibẹ nwọn o dide, oluku-
luku ninu agọ rẹ̀, nwọn o si fi iná kun ilu
yi.
11 O si ṣe, nigbati ogun awọn ara Kaldea
goke lọ kuro ni Jerusalemu nitori ogun
Farao,
12 Ni Jeremiah jade kuro ni Jerusalemu
lati lọ si ilẹ Benjamini lati pin ini lãrin
awọn enia.
13 Nigbati o si wà li ẹnu-bode Benja-
mini, balogun iṣọ kan wà nibẹ, orukọ ẹniti
ijẹ Irijah, ọmọ Ṣelemiah, ọmọ Hananiah;



Digitized by Google

on si mu Jeremiah woli, wipe, Iwọ nsa tọ̀ awọn ara Kaldea lọ.
14 Jeremiah si wipe: Eke! emi kò sa tọ awọn ara Kaldea lọ. Ṣugbọn kò gbọ́ tirẹ̀: bẹ̃ni Irijah mu Jeremiah, o si mu u tọ̀ awọn ijoye wá.
15 Nitorina ni awọn ijoye ṣe binu si Jeremiah, nwọn si lù u, nwọn si fi sinu tubu ni ile Jonatani, akọwe; nitori nwọn ti fi eyi ṣe ile túbu.
16 Bẹ̃ni Jeremiah lọ inu ile-túbu ati inu iyara ṣiṣokunkun. Jeremiah si wà nibẹ li ọjọ pupọ;
17 Nigbana ni Sedekiah, ọba ranṣẹ pè e: ọba si bere lọwọ rẹ̀ nikọkọ ni ile rẹ̀, o si wipe, Ọrọ ha wà lati ọdọ Oluwa? Jeremiah si wipe, O wà: o wi pe, nitori a o fi ọ le ọwọ ọba Babeli.
18 Pẹlupẹlu Jeremiah sọ fun Sedekiah, ọba, pe; Ẹṣẹ wo ni mo ṣẹ̀, tabi awọn iranṣẹ rẹ, tabi awọn enia yi, ti ẹnyin fi mi sinu ile túbu?
19 Nibo ni awọn woli nyin ha wà nisisiyi, awọn ti nsọtẹlẹ fun nyin, wipe, Ọba Babeli kì yio wá sọdọ nyin ati si ilẹ yi?
20 Nitorina gbọ́ nisisiyi, emi bẹ̀ ọ, oluwa mi, ọba, jẹ ki ẹ̀bẹ mi, emi bẹ̀ ọ, ki o wá si iwaju rẹ; ki iwọ ki o má jẹ ki emi pada si ile Jonatani akọwe, ki emi má ba kú nibẹ.
21 Sedekiah, ọba, si paṣẹ pe ki nwọn ki o fi Jeremiah pamọ sinu agbala ile-túbu, ati pe ki nwọn ki o ma fun u ni iṣu akara kọ̃kan lojojumọ, lati ita awọn alakara, titi gbogbo akara fi tan ni ilu. Jeremiah si wà li agbala ile-túbu.

## ORI 38.

NIGBANA ni Ṣefatiah, ọmọ Mattani, ati Gedaliah, ọmọ Paṣuri, ati Jukali, ọmọ Ṣelemiah, ati Paṣuri ọmọ Malkiah, gbọ́ gbogbo ọ̀rọ ti Jeremiah ti sọ fun gbogbo enia, wipe,
2 Bayi li Oluwa wi pe, ẹniti o ba joko ni ilu yi yio kú nipa idà, nipa ìyan, ati nipa àjakalẹ-àrun, ẹniti o ba si jade tọ̀ awọn ara Kaldea lọ yio yè; a o si fi ẹmi rẹ̀ fun u bi ikogun, yio si yè.
3 Bayi li Oluwa wi pe, lõtọ a o fi ilu yi le ọwọ ogun ọba Babeli, ẹniti yio si kó o.
4 Awọn ijoye si sọ fun ọba pe, Jẹ ki a pa ọkọnrin yi: nitori bayi li o mu ọwọ awọn ologun ti o kù ni ilu yi rọ, pẹlu ọwọ gbogbo enia, ni sisọ iru ọ̀rọ bayi fun wọn: nitori ọkọnrin yi kò wá alafia awọn enia yi, bikoṣe ibi wọn.
5 Sedekiah ọba, si wipe, Wò o, on wà li ọwọ nyin, nitori ọba kò le iṣe ohun kan lẹhin nyin.
6 Nwọn si mu Jeremiah, nwọn si sọ ọ sinu iho Malkiah ọmọ Hammeleki, ti o wà li agbala ile-túbu: nwọn fi okun sọ Jeremiah kalẹ sisalẹ. Omi kò si si ninu iho na, bikoṣe ẹrẹ̀: Jeremiah si rì sinu ẹrẹ̀ na.
7 Nigbati Ebedmeleki, ara Etiopia, iwẹfa kan, ti o wà ni ile ọba, gbọ́ pe, nwọn fi Jeremiah sinu iho: ọba joko nigbana li ẹnu-bode Benjamini;
8 Ebedmeleki si jade lati ile ọba lọ, o si sọ fun ọba wipe,
9 Oluwa mi, ọba! awọn ọkọnrin wọnyi ti ṣe ibi ni gbogbo eyi ti nwọn ti ṣe si Jeremiah woli pe, nwọn ti sọ ọ sinu iho; ebi yio si fẹrẹ pa a kú ni ibi ti o gbe wà: nitori onjẹ kò si mọ ni ilu.
10 Nigbana ni ọba paṣẹ fun Ebedmeleki, ara Etiopia, wipe, Mu ọgbọ̀n enia lọwọ lati ihin lọ, ki o si fà Jeremiah soke lati inu iho, ki o to kú.
11 Ebedmeleki si mu awọn enia na pẹlu rẹ̀, o si lọ si ilẹ ọba labẹ iyara iṣura, o si mu akisa ati oṣuka lati ibẹ wá, o si fi okùn sọ̀ wọn kalẹ si Jeremiah ninu iho.
12 Ebedmeleki, ara Etiopia, si sọ fun Jeremiah pe, Fi akisa ati oṣuka wọnyi si abẹ abia rẹ, lori okùn. Jeremiah si ṣe bẹ̃.
13 Bẹ̃ni nwọn fi okùn fà Jeremiah soke, nwọn si mu u goke lati inu iho wá: Jeremiah si wà li agbala ile tubu.
14 Nigbana ni Sedekiah, ọba, ranṣẹ, o mu Jeremiah woli, wá sọdọ rẹ̀ si ẹnu-ọ̀na kẹta ti o wà ni ile Oluwa: ọba si wi fun Jeremiah pe, Emi o bi ọ lere ohun kan: máṣe fi nkankan pamọ fun mi.
15 Jeremiah si wi fun Sedekiah pe, Bi emi ba sọ fun ọ, iwọ kì o ha pa mi nitõtọ? bi mo ba si fi imọran fun ọ, iwọ kì yio fetisi ti emi.
16 Sedekiah, ọba, si bura nikọkọ fun Jeremiah, wipe, Bi Oluwa ti wà, ẹni ti o da ẹmi wa yi, emi kì yio pa ọ, bẹ̃ni emi kì yio fi ọ le ọwọ awọn ọkọnrin wọnyi, ti nwá ẹmi rẹ.
17 Nigbana ni Jeremiah sọ fun Sedekiah pe; Bayi li Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi pe: Bi iwọ o ba jade nitõtọ tọ̀ awọn ijoye ọba Babeli lọ nigbana ni ọkàn rẹ yio yè, a kì yio si fi iná kun ilu yi; iwọ o si yè ati ile rẹ.
18 Ṣugbọn bi iwọ kì yio ba jade tọ awọn ijoye ọba Babeli lọ, nigbana ni a o fi ilu yi

Digitized by Google

le ọwọ awọn ara Kaldea, nwọn o si fi iná
kun u, iwọ kì yio si sala kuro li ọwọ wọn.
19 Sedekiah ọba, si sọ fun Jeremiah pe,
Ẹru awọn ara Juda ti o ya tọ awọn ara
Kaldea mbà mi, ki nwọn ki o má ba fi mi
le wọn lọwọ; nwọn a si fi mi ṣẹsin.
20 Ṣugbọn Jeremiah wipẹ, nwọn kì yio
si fi ọ le wọn lọwọ, emi bẹ̀ ọ, gbọ́ ọ̀rọ
Oluwa ti mo sọ fun ọ: yio si dara fun ọ,
ọkàn rẹ yio si yè.
21 Ṣugbọn bi iwọ ba kọ̀ lati jade lọ, eyi
li ohun ti Oluwa ti fi hàn mi:
22 Si wò o, gbogbo awọn obirin ti o kù
ni ile ọba Juda li a o mu tọ̀ awọn ijoye ọba
Babeli lọ, awọn obirin wọnyi yio si wipe,
Awọn ọrẹ rẹ ti tàn ọ jẹ, nwọn si ti bori rẹ:
ẹsẹ rẹ rì sinu ẹrẹ̀ wayi, nwọn pa ẹhin dà.
23 Nwọn o si mu gbogbo awọn aya rẹ
ati awọn ọmọ rẹ jade tọ awọn ara Kaldea
lọ: iwọ kì yio si sala kuro li ọwọ wọn, ọwọ
ọba Babeli yio si mu ọ: iwọ o si mu ki
nwọn ki o fi iná kun ilu yi.
24 Sedekiah si wi fun Jeremiah pe, Máṣe
jẹ ki ẹnikan mọ̀ niti ọ̀rọ wọnyi, ki iwọ má
ba kú.
25 Ṣugbọn bi awọn ijoye ba gbọ́ pe emi
ti ba ọ sọ̀rọ, bi nwọn ba si wá sọdọ rẹ, ti
nwọn sọ fun ọ pe, Sọ fun wa nisisiyi eyi ti
iwọ ti sọ fun ọba, máṣe fi pamọ fun wa,
awa kì o si pa ọ; ati eyi ti ọba sọ fun ọ
pẹlu:
26 Nigbana ni ki iwọ ki o wi fun wọn
pe, Emi mu ẹ̀bẹ mi wá siwaju ọba, pe ki o
má mu mi pada lọ si ile Jonatani, lati kú
sibẹ.
27 Gbogbo awọn ijoye si tọ̀ Jeremiah
wá, nwọn bi i lere: o si sọ fun wọn gẹgẹ bi
gbogbo ọ̀rọ wọnyi ti ọba ti palaṣẹ fun u.
Bẹ̃ni nwọn dakẹ nwọn si jọ̀rẹ̀; nitori ẹni-
kan kò gbọ́ ọ̀ran na.
28 Jeremiah si ngbe agbala ile-túbu titi
di ọjọ ti a kó Jerusalemu.

## ORI 39.

O SI ṣe, nigbati a kó Jerusalemu (li ọdun
kẹsan Sedekiah, ọba Juda, li oṣu kẹwa
ni Nebukadnessari, ọba Babeli, ati gbogbo
ogun rẹ̀ wá si Jerusalemu, nwọn si dó tì i.
2 Ati li ọdun kọkanla Sedekiah, li oṣu
kẹrin, li ọjọ kẹsan oṣu li a fọ ilu na.)
3 Gbogbo awọn ijoye ọba Babeli si wọle,
nwọn si joko li ẹnu-bode ãrin, ani Nergali-
Ṣareseri, Samgari-nebo, Sarsikimu, olori
iwẹfa, Nergali-Ṣareseri, olori amoye, pẹlu
gbogbo awọn ijoye ọba Babeli iyokù.
4 O si ṣe, nigbati Sedekiah, ọba Juda,
ati gbogbo awọn ologun ri wọn, nigbana ni
nwọn sá, nwọn si jade kuro ni ilu li oru,
nwọn gba ọ̀na ọgbà ọba ati ẹnu-bode lãrin
odi mejeji, nwọn si jade lọ li ọ̀na pẹtẹlẹ.
5 Ṣugbọn ogun awọn ara Kaldea lepa
wọn, nwọn si ba Sedekiah, ọba, ni pẹtẹlẹ
Jeriko; nigbati nwọn si mu u, nwọn mu u
goke wá sọdọ Nebukadnessari, ọba Babeli,
ni Ribla ni ilẹ Hamati, nibiti o sọ̀rọ idajọ
lori rẹ̀.
6 Nigbana ni ọba Babeli pa awọn ọmọ
Sedekiah ni Ribla, niwaju rẹ̀; ọba Babeli
si pa gbogbo awọn ọlọla Juda pẹlu.
7 Pẹlupẹlu o fọ Sedekiah li oju, o si fi
ẹ̀wọn dè e, lati mu u lọ si Babeli.
8 Awọn ara Kaldea si fi ile ọba ati ile
awọn enia joná, nwọn si wó odi Jerusalemu
lulẹ.
9 Nebusaradani, balogun iṣọ, si kó iyo-
kù awọn enia ti o kù ni ilu ni igbekun lọ
si Babeli, pẹlu awọn ti o ti ya lọ, ti o ya
sọdọ rẹ̀, pẹlu awọn enia iyokù ti o kù.
10 Ṣugbọn Nebusaradani, balogun iṣọ,
si mu diẹ ninu awọn enia, ani awọn talaka
ti kò ni nkan rara, joko ni ilẹ Juda, o si fi
ọgba-àjara ati oko fun wọn li àkoko na.
11 Nebukadnessari, ọba Babeli, si paṣẹ
fun Nebusaradani, balogun iṣọ, niti Jere-
miah, wipe,
12 Mu u, ki o si bojuto o, má si ṣe e ni
ibi kan; ṣugbọn gẹgẹ bi on ba ti sọ fun ọ,
bẹ̃ni ki iwọ ki o ṣe fun u.
13 Bẹ̃ni Nebusaradani, balogun iṣọ, ati
Nebuṣaṣbani, olori iwẹfa, ati Nergali Ṣare-
seri, olori amoye, ati gbogbo ijoye ọba Ba-
beli, si ranṣe,
14 Ani nwọn ranṣẹ nwọn si mu Jeremiah
jade ni àgbala ile-tubu, nwọn si fi fun Ge-
daliah, ọmọ Ahikamu, ọmọ Ṣafani, pe ki
o mu u lọ si ile: bẹ̃ni o ngbe ãrin awọn
enia.
15 Ọrọ Oluwa si tọ̀ Jeremiah wá, nigba-
ti a se e mọ ninu àgbala ile-túbu, wipe,
16 Lọ, ki o si sọ fun Ebedmeleki, ara
Etiopia, wipe: Bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun, Ọlọrun Israeli wi pe, wò o, emi o mu
ọ̀rọ mi wá sori ilu yi fun ibi, kì isi ṣe fun
rere; nwọn o si ṣẹ niwaju rẹ li ọjọ na.
17 Ṣugbọn emi o gbà ọ li ọjọ na, li
Oluwa wi: a kì o si fi ọ le ọwọ awọn enia
na ti iwọ bẹ̀ru.
18 Nitori emi o gbà ọ là nitõtọ, iwọ kì
o si ti ipa idà ṣubu, ṣugbọn ẹ̀mi rẹ yio jẹ
bi ikogun fun ọ: nitoripe iwọ ti gbẹkẹ rẹ
le mi, li Oluwa wi.

Digitized by Google

## ORI 40.

ỌRỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá lati ọdọ Oluwa, lẹhin ti Nebusaradani, balogun iṣọ, ti ranṣẹ pè e lati Rama. Nitori nigbati o mu u, a fi ẹwọn dè e lãrin gbogbo awọn igbekun Jerusalemu ati Juda, ti a kó ni igbekun lọ si Babeli.
2 Balogun iṣọ si mu Jeremiah, o si wi fun u pe, Oluwa, Ọlọrun rẹ, ti sọ ibi yi si ilu yi.
3 Oluwa si ti mu u wá, o si ṣe gẹgẹ bi o ti wi: nitoripe ẹnyin ti ṣẹ̀ si Oluwa, ẹ kò si gbọ́ ohùn rẹ̀, nitorina ni nkan yi ṣe de ba nyin.
4 Njẹ nisisiyi, wò o, mo tú ọ silẹ li oni kuro ninu ẹ̀wọn ti o wà li ọwọ rẹ: bi o ba dara li oju rẹ lati ba mi lọ si Babeli, kalọ, emi o boju to ọ: ṣugbọn bi kò ba dara li oju rẹ lati ba mi lọ si Babeli, jọwọ rẹ̀; wò o, gbogbo ilẹ li o wà niwaju rẹ, ibi ti o ba dara ti o ba si tọ li oju rẹ lati lọ, lọ sibẹ.
5 Bi bẽkọ, pada tọ̀ Gedaliah, ọmọ Ahikamu, ọmọ Ṣafani, ẹniti ọba Babeli ti fi jẹ bãlẹ lori ilu Juda, ki o si mã ba a gbe lãrin ọpọ enia, tabi ibikibi ti o ba tọ li oju rẹ, lati lọ, lọ sibẹ̀. Balogun iṣọ si fun u li onjẹ ati ẹbun; o si jọrẹ̀ lọwọ.
6 Jeremiah si lọ sọdọ Gedaliah, ọmọ Ahikamu, ni Mispa; o si mba a gbe lãrin awọn enia, ti o kù ni ilẹ na.
7 Njẹ nigbati gbogbo awọn olori ogun, ti o wà li oko, awọn ati awọn ọkọnrin wọn, gbọ́ pe ọba Babeli ti fi Gedaliah, ọmọ Ahikamu, jẹ bãlẹ ni ilẹ na, o si ti fi awọn ọkọnrin fun u, ati awọn obirin, ati awọn ọmọde, ati ninu awọn talaka ilẹ na, ninu awọn ti a kò kó lọ ni igbekun si Babeli.
8 Nwọn tọ̀ Gedaliah wá ni Mispa, ani Iṣmaeli, ọmọ Netaniah, ati Johanani, ati Jonatani, awọn ọmọ Karea, ati Seraiah, ọmọ Tanhumeti, ati awọn ọmọ Efai, ara Netofa, ati Jesaniah, ọmọ ara Maaka, awọn ati awọn ọkọnrin wọn,
9 Gedaliah, ọmọ Ahikamu, ọmọ Ṣafani, si bura fun wọn ati fun awọn ọkọnrin wọn, wipe: Ẹ má bẹ̀ru lati sìn awọn ara Kaldea: ẹ gbe ilẹ na, ki ẹ si mã sin ọba Babeli, yio si dara fun nyin.
10 Bi o ṣe ti emi, wò o, emi o ma gbe Mispa, lati sìn awọn ara Kaldea, ti yio tọ wa wá; ṣugbọn ẹnyin ẹ kó ọti-waini jọ, ati eso-igi, ati ororo, ki ẹ si fi sinu ohun-elo nyin, ki ẹ si gbe inu ilu nyin ti ẹnyin ti gbà.
11 Pẹlupẹlu gbogbo awọn ara Juda, ti o wà ni Moabu, ati lãrin awọn ọmọ Ammoni, ati ni Edomu, ati awọn ti o wà ni gbogbo ilẹ wọnni gbọ́ pe, ọba Babeli ti fi iyokù silẹ fun Juda, ati pe o ti fi Gedaliah, ọmọ Ahikamu, ọmọ Ṣafani, ṣolori wọn;
12 Gbogbo awọn ara Juda si pada lati ibi gbogbo wá ni ibi ti a ti lé wọn si, nwọn si wá si ilẹ Juda sọdọ Gedaliah si Mispa, nwọn si kó ọti-waini ati eso igi jọ pupọpupọ.
13 Ṣugbọn Johanani, ọmọ Karea, ati gbogbo awọn olori ogun ti o wà li oko, tọ̀ Gedaliah wá si Mispa.
14 Nwọn si wi fun u pe, Iwọ ha mọ̀ dajudaju pe: Baalisi, ọba awọn ọmọ Ammoni, ti ran Iṣmaeli, ọmọ Netaniah, lati pa ọ? Ṣugbọn Gedaliah, ọmọ Ahikamu, kò gbà wọn gbọ́.
15 Nigbana ni Johanani, ọmọ Karea, si sọ nikọkọ fun Gedaliah ni Mispa pe, Jẹ ki emi lọ, mo bẹ ọ, emi o si pa Iṣmaeli, ọmọ Netaniah, ẹnikan kì yio si mọ̀: Ẽṣe ti on o fi pa ọ, ti gbogbo awọn ara Juda ti a kojọ tì ọ, yio tuka, ati iyokù Juda yio ṣegbe?
16 Ṣugbọn Gedaliah, ọmọ Ahikamu, sọ fun Johanani, ọmọ Karea pe, Iwọ kò gbọdọ ṣe nkan yi, nitori eke ni iwọ ṣe mọ Iṣmaeli.

## ORI 41.

O SI ṣe li oṣu keje Iṣmaeli, ọmọ Netaniah ọmọ Elișama, ninu iru-ọmọ ọba, ati awọn ijoye ọba, ati ọkọnrin mẹwa pẹlu rẹ̀, nwọn tọ̀ Gedaliah, ọmọ Ahikamu, wá ni Mispa: nibẹ ni nwọn jumọ jẹun ni Mispa.
2 Nigbana ni Iṣmaeli, ọmọ Netaniah, ati awọn ọkọnrin mẹwa ti nwọn wà pẹlu rẹ̀, nwọn fi idà kọlu Gedaliah, ọmọ Ahikamu, ọmọ Ṣafani, nwọn si pa a, on ẹniti ọba Babeli ti fi jẹ bãlẹ lori ilẹ na.
3 Pẹlupẹlu Iṣmaeli pa gbogbo awọn ara Juda ti o wà pẹlu rẹ̀, ani pẹlu Gedaliah, ni Mispa, ati awọn ara Kaldea, ti a ri nibẹ, awọn ologun.
4 O si ṣe li ọjọ keji lẹhin ti o ti pa Gedaliah, ti ẹnikan kò si mọ̀.
5 Nigbana ni ọgọrin ọkọnrin wá lati Ṣekemu, lati Ṣilo, ati lati Samaria, ti nwọn fá irungbọn wọn, nwọn fà aṣọ wọn ya, nwọn si ṣá ara wọn lọgbẹ, nwọn mu ọrẹ-ẹbọ ati turari li ọwọ wọn, lati mu u wá si ile Oluwa.
6 Iṣmaeli, ọmọ Netaniah, si jade lati Mispa lọ ipade wọn, bi o ti nlọ, o nsọkun:

Digitized by Google

o si ṣe, bi o ti pade wọn, o wi fun wọn pe,
Ẹ jẹ ki a lọ sọdọ Gedaliah, ọmọ Ahikamu.
7 O si ṣe, nigbati nwọn de ãrin ilu, ni
Iṣmaeli, ọmọ Netaniah, pa wọn, on, ati
awọn ọkọnrin ti o wà pẹlu rẹ̀ si sọ wọn
sinu iho.
8 Ṣugbọn ọkọnrin mẹwa wà lãrin wọn ti
nwọn sọ fun Iṣmaeli pe, máṣe pa wa: ni-
tori awa ni iṣura li oko, ti alikama, ati ti
ọka barli, ati ti ororo, ati oyin. Bẽli o
jọwọ wọn, kò si pa wọn pẹlu awọn arakọn-
rin wọn.
9 Ati iho na ninu eyi ti Iṣmaeli ti sọ
gbogbo okú ọkọnrin wọnyi si, awọn ti o ti
pa pẹlu Gedaliah, ni eyiti Asa, ọba, ti ṣe
nitori ibẹ̀ru Baaṣa, ọba Israeli: Iṣmaeli,
ọmọ Netaniah, si fi awọn ti a pa kún u.
10 Iṣmaeli si kó gbogbo iyokù awọn enia
ti o wà ni Mispa ni igbekun, awọn ọmọ-
birin ọba, ati gbogbo enia ti o kù ni Mispa,
awọn ti Nebusaradani, balogun iṣọ, ti fi le
Gedaliah, ọmọ Ahikamu lọwọ: Iṣmaeli,
ọmọ Netaniah, si kó wọn ni igbekun, o si
kuro nibẹ lati rekọja lọ sọdọ awọn ọmọ
Ammoni.
11 Ṣugbọn nigbati Johanani, ọmọ Karea,
ati gbogbo awọn olori ogun ti o pẹlu rẹ̀,
gbọ́ ibi ti Iṣmaeli, ọmọ Netaniah ti ṣe,
12 Nigbana ni nwọn kó gbogbo awọn
ọkọnrin, nwọn si lọ iba Ismaeli, ọmọ Ne-
taniah jà, nwọn si ri i li ẹba omi nla ti o
wà ni Gibeoni.
13 O si ṣe, nigbati gbogbo awọn enia ti
o wà pẹlu Iṣmaeli ri Johanani, ọmọ Karea,
ati gbogbo awọn olori ogun ti o pẹlu rẹ̀,
nwọn si yọ̀,
14 Bẽni gbogbo awọn enia, ti Iṣmaeli ti
kó lọ ni igbekun lati Mispa, yi oju wọn,
nwọn si yipada, nwọn si lọ sọdọ Johanani,
ọmọ Karea.
15 Ṣugbọn Iṣmaeli, ọmọ Netaniah, bọ́
lọwọ Johanani pẹlu ọkọnrin mẹjọ, o si lọ
sọdọ awọn ọmọ Ammoni.
16 Johanani, ọmọ Karea, ati gbogbo
awọn olori ogun ti o wà pẹlu rẹ̀, si mu gbo-
gbo iyokù awọn enia ti o ti gbà lowọ Iṣma-
eli, ọmọ Netaniah, lati Mispa, lẹhin ti o ti
pa Gedaliah, ọmọ Ahikamu ani, akọni
ọkọnrin ogun, ati awọn obirin, ati awọn
ọmọde, ati awọn iwẹfa, awọn ti o ti tun
mu pada lati Gibeoni wá:
17 Nwọn si kuro nibẹ, nwọn si joko ni
ibugbe Kinhamu, ti o wà lẹba Betlehemu,
lati lọ ide Egipti,
18 Nitoriti ẹ̀ru ba wọn niwaju awọn ara
Kaldea, nitoriti Iṣmaeli ọmọ Netaniah, ti
pa Gedaliah, ọmọ Ahikamu ẹniti ọba Ba-
beli fi jẹ bãlẹ ni ilẹ na.

## ORI 42.

NIGBANA ni gbogbo awọn olori ogun,
ati Johanani, ọmọ Karea, ati Jesan-
iah, ọmọ Hoṣaiah, ati gbogbo awọn enia
lati ẹni-kekere de ẹni-nla, nwọn wá.
2 Nwọn si sọ fun Jeremiah woli, pe,
Awa bẹ ọ, jẹ ki ẹ̀bẹ wa ki o wá siwaju rẹ,
ki o si gbadura fun wa si Oluwa Ọlọrun rẹ,
ani fun gbogbo iyokù yi; (nitori lati inu
ọ̀pọlọpọ, diẹ li awa kù, gẹgẹ bi oju rẹ ti ri
wa:)
3 Ki Oluwa Ọlọrun rẹ le fi ọ̀na hàn wa
ninu eyi ti awa iba rìn, ati ohun ti awa iba
ṣe.
4 Jeremiah, woli, si wi fun wọn pe, emi
gbọ́; wò o, emi o gbadura si Oluwa Ọlọ-
run nyin gẹgẹ bi ọ̀rọ nyin; yio si ṣe, pe
ohunkohun ti Oluwa yio fi da nyin lohùn
emi o sọ ọ fun nyin; emi kì o ṣẹ nkankan
kù fun nyin.
5 Nwọn si wi fun Jeremiah pe, ki Olu-
wa ki o ṣe ẹlẹri otitọ ati ododo lãrin wa, bi
awa kò ba ṣe gẹgẹ bi gbogbo ọ̀rọ ti Oluwa,
Ọlọrun rẹ, yio rán ọ si wa.
6 Iba ṣe rere, iba ṣe ibi, awa o gbà ohùn
Oluwa Ọlọrun wa gbọ́, sọdọ ẹniti awa rán
ọ: ki o le dara fun wa, bi awa ba gbà ohùn
Oluwa Ọlọrun wa gbọ́.
7 O si ṣe lẹhin ọjọ mẹwa li ọ̀rọ Oluwa tọ̀
Jeremiah wá.
8 Nigbana ni o pè Johanani, ọmọ Karea,
ati gbogbo awọn olori ogun ti o wà pẹlu rẹ̀,
ati gbogbo awọn enia lati ẹni-kekere titi de
ẹni-nla.
9 O si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa
Ọlọrun Israeli wi, sọdọ ẹniti ẹnyin rán mi,
lati mu ẹ̀bẹ nyin wá siwaju rẹ̀;
10 Bi ẹnyin o ba gbe ilẹ yi lõtọ, nigbana
ni emi o gbe nyin ro emi kì yio si fà nyin
lulẹ, emi o si gbìn nyin, emi kì yio si fà
nyin tu: nitori emi yi ọkàn pada niti ibi ti
emi ti ṣe si nyin.
11 Ẹ má bẹ̀ru ọba Babeli, ẹniti ẹnyin
mbẹ̀ru: ẹ máṣe bẹ̀ru rẹ̀, li Oluwa wi: ni-
tori emi wà pẹlu nyin lati ràn nyin lọwọ,
ati lati gbà nyin li ọwọ rẹ̀.
12 Emi o si fi ãnu hàn fun nyin, ki on
ki o le ṣãnu fun nyin, ki o si mu ki ẹnyin
pada si ilẹ nyin.
13 Ṣugbọn bi ẹnyin ba wipe, Awa kì yio
gbe ilẹ yi, ti ẹnyin kò si gbà ohùn Oluwa
Ọlọrun nyin gbọ́.
14 Wipe, bẹ̃kọ̀; ṣugbọn awa fẹ lọ si ilẹ

Digitized by Google

Egipti, nibiti awa kì yio ri ogunkogun, ti
a kì o si gbọ́ iró fère, ti ebi onjẹ kò ni ipa
wa, nibẹ li awa o si mã gbe:
15 Njẹ nisisiyi, nitorina, ẹ gbọ́ ọ̀rọ
Oluwa, ẹnyin iyokù Juda, Bayi li Oluwa
awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi pe, Bi
ẹ ba gbe oju nyin patapata le ati lọ si
Egipti, bi ẹnyin ba lọ lati ṣe atipo nibẹ,
16 Yio si ṣe, idà ti ẹnyin bẹ̀ru, yio si le
nyin ba ni ilẹ Egipti; ati ìyan, ti ẹnyin
bẹ̀ru, yio tẹle nyin girigiri nibẹ ni Egipti;
nibẹ li ẹnyin o si kú.
17 Bẽni gbogbo awọn ọkọnrin ti nwọn
gbe oju wọn si ati lọ si Egipti lati ṣatipo
nibẹ; nwọn o kú, nipa idà, nipa ìyan,
tabi nipa àjakalẹ-arun, ẹnikẹni ninu wọn
kì yio kù, tabi kì o sala kuro ninu ibi ti
emi o mu wá sori wọn.
18 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun,
Ọlọrun Israeli wi, pe, Gẹgẹ bi emi ti dà
ibinu mi ati irunu mu sori awọn olugbe
Jerusalemu; bẽni emi o dà irunu mi le
nyin lori, ẹnyin ti yio lọ si Egipti: ẹnyin
o si di ẹni-ègun, ati ẹni-iyanu, ati ẹ̀gan, ati
ẹ̀sin; ẹnyin kì yio si tun ri ibi yi mọ.
19 Oluwa ti sọ niti nyin, ẹnyin iyokù
Juda, ẹ má lọ si Egipti: ẹ mọ̀ dajudaju pe
emi ti jẹri si nyin li oni yi.
20 Nitori ọkàn nyin li ẹnyin tanjẹ,
nigbati ẹnyin rán mi si Oluwa, Ọlọrun
nyin, wipe, Gbadura fun wa si Oluwa,
Ọlọrun wa: ati gẹgẹ bi gbogbo eyi ti
Oluwa Ọlọrun wa yio wi, bẽni ki o sọ fun
wa, awa o si ṣe e.
21 Emi si ti sọ fun nyin loni; ṣugbọn
ẹnyin kò gbọ́ ohùn Oluwa, Ọlọrun nyin,
ati gbogbo eyi ti on ti ran mi si nyin.
22 Njẹ nitorina, ẹ mọ̀ dajudaju pe, ẹnyin
o kú nipa idà, nipa ìyan, ati nipa àjakalẹ-
arun, ni ibẹ na nibiti ẹnyin fẹ lati lọ iṣe
atipo.

## ORI 43.

OSI ṣe, nigbati Jeremiah pari ọ̀rọ isọ fun
gbogbo awọn enia, ani gbogbo ọ̀rọ
Oluwa Ọlọrun wọn, eyiti Oluwa Ọlọrun
wọn ti rán a si wọn, ani gbogbo ọ̀rọ wọnyi.
2 Nigbana ni Asariah, ọmọ Hoṣaiah, ati
Johanani, ọmọ Karea, ati gbogbo awọn
agberaga enia, wi fun Jeremiah pe, Iwọ ṣe
eke! Oluwa, Ọlọrun wa, kò ran ọ lati
wipe, Ẹ má lọ si Egipti lati ṣatipo nibẹ.
3 Ṣugbọn Baruku, ọmọ Neriah, li o fi
ọ̀rọ si ọ li ẹnu si wa, nitori lati fi wa le
awọn ara Kaldea lọwọ, lati pa wa ati lati
kó wa ni igbekun lọ si Babeli.
4 Bẽni Johanani, ọmọ Karea, ati gbogbo
awọn olori ogun, ati gbogbo awọn enia, kò
gbà ohùn Oluwa gbọ́, lati mã gbe ilẹ Juda,
5 Johanani, ọmọ Karea, ati gbogbo
awọn olori ogun, si mu gbogbo iyokù Juda,
ti nwọn pada lati gbogbo orilẹ-ède wá, ni
ibi ti a ti le wọn si, lati ma gbe ilẹ Juda;
6 Awọn ọkọnrin, ati awọn obirin, ati
awọn ọmọde, ati awọn ọmọbirin ọba, ati
gbogbo enia ti Nebusaradani, balogun iṣọ,
ti kù silẹ lọdọ Gedaliah, ọmọ Ahikamu,
ọmọ Ṣafani, ati Jeremiah woli, ati Baruku,
ọmọ Neriah,
7 Nwọn si wá si ilẹ Egipti: nitori nwọn
kò gbà ohùn Oluwa gbọ́: bayi ni nwọn wá
si Tafanesi.
8 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Jeremiah wá
ni Tafanesi, wipe,
9 Mu okuta nla li ọwọ rẹ ki o si fi wọn
pamọ sinu amọ̀, ni ile-inà briki ti o wà ni
ẹnu-ọ̀na ile Farao ni Tafanesi, li oju awọn
ọkọnrin Juda.
10 Ki o si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa
awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi, pe, wò
o, emi o ranṣẹ, emi o si mu Nebukadnessa-
ri, ọba Babeli, iranṣẹ mi, emi o si gbe itẹ
rẹ̀ kalẹ lori okuta wọnyi, ti emi ti fi pamọ;
on o si tẹ itẹ ọla rẹ̀ lori wọn.
11 Nigbati o ba si de, on o kọlu ilẹ
Egipti, on o si fi ti ikú, fun ikú: ti igbe-
kun, fun igbekun; ati ti idà, fun idà.
12 Emi o si dá iná kan ni ile awọn oriṣa
Egipti; on o si sun wọn, yio si kó wọn lọ;
on o si fi ilẹ Egipti wọ ara rẹ̀ laṣọ gẹgẹ bi
oluṣọ-agutan ti iwọ̀ aṣọ rẹ̀; yio si jade lati
ibẹ lọ li alafia.
13 Yio si fọ́ ere ile-õrùn, ti o wà ni ilẹ
Egipti tutu, yio si fi iná kun ile awọn oriṣa
awọn ara Egipti.

## ORI 44.

Ọ̀RỌ ti o tọ̀ Jeremiah wá fun gbogbo
awọn ara Juda ti ngbe ilẹ Egipti, ti
ngbe Migdoli, ati Tafanesi, ati Nofu, ati
ilẹ Patrosi, wipe,
2 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun
Israeli wi pe, ẹnyin ti ri gbogbo ibi ti emi
ti mu wá sori Jerusalemu, ati sori gbogbo
ilu Juda; si wò o, ahoro ni nwọn li oni yi,
ẹnikan kò si gbe inu wọn.
3 Nitori ìwa-buburu wọn ti nwọn ti hù
lati mu mi binu, ni lilọ lati sun turari ati
lati sìn awọn ọlọrun miran, ti nwọn kò mọ̀,
awọn, tabi ẹnyin, tabi awọn baba nyin.
4 Emi si ran gbogbo awọn iranṣẹ mi,

Digitized by Google

awọn woli si nyin, emi dide ni kutukutu,
mo rán wọn, wipe, A ! ẹ máṣe ohun irira
yi ti emi korira.
5 Ṣugbọn nwọn kò gbọ́, bẽni nwọn kò
tẹti wọn silẹ lati yipada kuro ninu ìwa-
buburu wọn, ki nwọn ki o má sun turari
fun ọlọrun miran.
6 Nitorina ni mo ṣe dà ìrunu mi ati ibi-
nu mi jade, a si daná rẹ̀ ni ilu Juda, ati ni
ita Jerusalemu : nwọn si di ofo ati ahoro,
gẹgẹ bi ti oni yi.
7 Njẹ nisisiyi, bayi li Oluwa, Ọlọrun
awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi pe,
nitori kini ẹ ṣe da ẹ̀ṣẹ nla yi si ọkàn nyin,
lati ke ninu nyin ani ọkọnrin ati obirin,
ati ọmọde ati ọmọ-ọmu, kuro lãrin Juda,
lati má kù iyokú fun nyin ;
8 Ninu eyiti ẹnyin fi iṣẹ ọwọ nyin mu
mi binu, ni sisun turari fun ọlọrun miran
ni ilẹ Egipti, nibiti ẹnyin lọ lati ṣatipo, ki
ẹ le ke ara nyin kuro, ati ki ẹ le jẹ ẹni-
ègun ati ẹsin, lãrin gbogbo orilẹ-ède ilẹ
aiye ?
9 Ẹnyin ha ti gbagbe ìwa-buburu awọn
baba nyin, ati ìwa-buburu awọn ọba Juda,
ati ìwa-buburu awọn aya wọn, ati ìwa-
buburu ẹnyin tikara nyin, ati ìwa-buburu
awọn aya nyin, ti nwọn ti hù ni ilẹ Juda,
ati ni ita Jerusalemu.
10 Nwọn kò rẹ̀ ara wọn silẹ titi di oni
yi, bẽni wọn kò bẹru, tabi ki nwọn ki o-
rìn ninu ofin mi, tabi ninu ilana mi ti emi
gbe kalẹ niwaju nyin ati niwaju awọn baba
nyin.
11 Nitorina bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun, Ọlọrun Israeli, wi pe, wò o emi doju
mi kọ nyin fun ibi, ati lati ke gbogbo Juda
kuro.
12 Emi o si mu gbogbo iyokù Juda, ti o
ti gbe oju wọn si ati lọ si ilẹ Egipti, lati
ṣatipo nibẹ, gbogbo wọn ni yio si run, nwọn
o si ṣubu ni ilẹ Egipti ; nwọn o si run nipa
idà ati nipa ìyan, nwọn o kú lati ẹni-
kekere wọn titi de ẹni-nla wọn, nipa idà,
ati nipa ìyan : nwọn o si di ẹni-ègun, ẹni-
iyanu, ati ẹni-ẹgan, ati ẹsin.
13 Nitori emi o bẹ̀ awọn ti ngbe Egipti
wò, gẹgẹ bi emi ti jẹ Jerusalemu niya, nipa
idà, nipa ìyan, ati nipa àjakalẹ-arun ;
14 Kì o si si ẹniti o sala, ati ẹniti o kù,
fun awọn iyokù Juda, ti o wọ ilẹ Egipti
lati ma ṣatipo nibẹ, ti yio pada si ilẹ Juda,
si eyiti nwọn ni ifẹ ati pada lọ igbe ibẹ :
nitori kò si ọkan ti yio pada bikoṣe iru
awọn ti o sala.
15 Nigbana ni gbogbo awọn ọkọnrin ti
nwọn mọ̀ daju pe, awọn aya wọn ti sun
turari fun ọlọrun miran, ati gbogbo awọn
obirin ti o duro nibẹ, apejọ nla, ati gbogbo
awọn enia ti ngbe ilẹ Egipti ani ni Patrosi,
da Jeremiah lohùn, wipe,
16 Ọ̀rọ ti iwọ sọ fun wa li orukọ Oluwa,
awa kì yio feti si tirẹ.
17 Ṣugbọn dajudaju awa o ṣe ohunkohun
ti o jade lati ẹnu wa wá, lati sun turari fun
ayaba ọrun, ati lati da ẹbọ ohun mimu fun
u, gẹgẹ bi awa ti ṣe, awa, ati awọn baba
wa, awọn ọba wa, ati awọn ijoye wa ni ilu
Juda, ati ni ita Jerusalemu : nigbana awa
ni onjẹ pupọ, a si ṣe rere, a kò si ri ibi.
18 Ṣugbọn lati igba ti awa ti fi sisun
turari fun ayaba ọrun silẹ, ati lati da ẹbọ
ohun mimu fun u, awa ti ṣalaini ohun
gbogbo, a si run nipa idà ati nipa ìyan.
19 Ati nigbati awa sun turari fun ayaba
ọrun ti a si da ẹbọ ohun mimu fun u, lẹhin
awọn ọkọ wa ni awa ha dín akara didùn rẹ̀
lati bọ ọ, ti a si da ẹbọ ohun mimu fun u
bi ?
20 Nigbana ni Jeremiah sọ fun gbogbo
awọn enia, fun awọn ọkọnrin, ati fun awọn
obirin, ati fun gbogbo awọn enia ti o ti fun
u li èsi yi wipe.
21 Turari ti ẹnyin sun ni ilu Juda ati ni
ita Jerusalemu, ẹnyin ati awọn baba nyin,
awọn ọba nyin, ati awọn ijoye nyin, ati
awọn enia ilẹ na, Oluwa kò ha ranti rẹ̀, kò
ha si wá si ọkàn rẹ̀ ?
22 Tobẹ̃ ti Oluwa kò le rọju pẹ mọ, ni-
tori buburu iṣe nyin, ati nitori ohun irira
ti ẹnyin ti ṣe ; bẽni ilẹ nyin di ahoro, ati
iyanu ati ègun, laini olugbe, bi o ti ri li
oni yi.
23 Nitori ti ẹnyin ti sun turari, ati
nitori ti ẹnyin ṣẹ̀ si Oluwa, ti ẹnyin kò gbà
ohùn Oluwa gbọ́, ti ẹ kò rin ninu ofin rẹ̀,
ati ninu ilana rẹ̀, ati ninu ọ̀rọ ẹri rẹ̀ ; nito-
rina ni ibi yi ṣe de si nyin, bi o ti ri li oni
yi.
24 Jeremiah sọ pẹlu fun gbogbo awọn
enia, ati fun gbogbo awọn obirin na pe, ẹ
gbọ́ ọ̀rọ Oluwa gbogbo Juda ti o wà ni ilẹ
Egipti :
25 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọ-
run Israeli sọ, wipe, Ẹnyin ati awọn aya
nyin, ẹnyin fi ẹnu nyin sọ̀rọ, ẹ si fi ọwọ
nyin mu ṣẹ, ẹ si wipe, lõtọ awa o san ẹ̀jẹ́
wa ti awa ti jẹ, lati sun turari fun ayaba
ọrun, ati lati da ẹbọ ohun mimu fun u, njẹ
ni pipamọ, ẹ pa ẹ̀jẹ́ nyin mọ, ati ni sisan ẹ
san ẹ̀jẹ́ nyin.
26 Nitorina ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa, gbogbo

Digitized by Google

Juda ti ngbe ilẹ Egipti, sa wò o, emi ti fi
oruko nlanla mi bura, li Oluwa wi, pé, a
ki yio pè orukọ mi li ẹnu ọkọnrin-kọnrin
Juda ni gbogbo ilẹ Egipti, wipe, Oluwa,
Ọlọrun wà.

27 Wò o, emi o ṣọ wọn fun ibi, kì si iṣe
fun rere: ati gbogbo awọn ọkọnrin Juda
ti o wà ni ilẹ Egipti ni a o run nipa idà,
ati nipa ìyan, titi nwọn o fi tan.

28 Ati awọn ti o sala lọwọ idà, yio pada
ni iye diẹ lati ilẹ Egipti si ilẹ Juda; ati
gbogbo iyokù Juda, ti o lọ si ilẹ Egipti
lati ṣatipo nibẹ, yio mọ̀ ọ̀rọ tani yio duro,
temi, tabi ti wọn.

29 Eyi ni yio si jẹ àmi fun nyin, li
Oluwa wi, pe, emi o jẹ nyin niya ni ibiyi,
ki ẹnyin le mọ̀ pe: ọ̀rọ mi yio duro daju-
daju si nyin fun ibi:

30 Bayi li Oluwa wi; wò o, emi o fi
Farao-hofra, ọba Egipti, le ọwọ awọn ọta
rẹ̀, ati le ọwọ awọn ti nwá ẹmi rẹ̀; gẹgẹ bi
emi ti fi Sedekiah, ọba Juda, le ọwọ Ne-
bukadnessari, ọba Babeli ọta rẹ̀, ti o si wá
ẹmi rẹ̀.

## ORI 45.

ỌRỌ ti Jeremiah, woli, sọ fun Baruku,
ọmọ Neriah nigbati o ti kọ ọ̀rọ wọnyi
sinu iwe tan li ẹnu Jeremiah li ọdun kẹrin
Jehoiakimu, ọmọ Josiah, ọba Juda, wipe,

2 Bayi li Oluwa, Ọlọrun Israeli, wi fun
ọ, iwọ Baruku;

3 Iwọ wipe, Egbé ni fun mi nisisiyi!
nitori ti Oluwa ti fi ibanujẹ kún ikãnu mi;
ãrẹ̀ mu mi ninu ẹ̀dun mi, emi kò si ri
isimi.

4 Bayi ni ki iwọ sọ fun u, Oluwa wi
bayi; pe, Wò o, eyi ti emi ti kọ́, li emi o
wó lulẹ, ati eyi ti emi ti gbìn li emi o fà
tu, ani gbogbo ilẹ yi.

5 Iwọ ha si mbere ohun nla fun ara rẹ?
máṣe bere: nitori, wò o, emi o mu ibi wá
sori gbogbo ẹran-ara, li Oluwa wi: ṣugbọn
ẹmi rẹ li emi o fi fun ọ bi ikogun ni gbogbo
ibiti iwọ ba lọ si.

## ORI 46.

ỌRỌ Oluwa ti o tọ̀ Jeremiah, woli wá si
awọn orilẹ-ède.

2 Si Egipti, si ogun Farao-Neko, ọba
Egipti, ti o wà lẹba odò Ferate ni iha
Karkemiṣi, ti Nebukadnessari, ọba Babeli,
kọlu ni ọdun kẹrin Jehoiakimu, ọmọ
Josiah, ọba Juda.

3 Ẹ mura apata ati asà, ẹ si sunmọ tosi
si oju ìja,

4 Ẹ di ẹṣin ni gãri; ẹ gùn wọn, ẹnyin
ẹlẹṣin, ẹ duro lẹsẹsẹ ninu akoro nyin; ẹ
dan ọ̀kọ, ẹ wọ ẹwu irin.

5 Ẽṣe ti emi ti ri wọn ni ibẹ̀ru ati ni
ipẹhinda? awọn alagbara wọn li a lù bolẹ,
nwọn sa, nwọn kò si wò ẹhin: ẹ̀ru yika
kiri, li Oluwa wi.

6 Ẹni ti o yara, ki yio salọ, alagbara
ọkọnrin ki yio si sala: ni iha ariwa lẹba
odò Ferate ni nwọn o kọsẹ̀, nwọn o si
ṣubu.

7 Tani eyi ti o goke wá bi odò, ti omi
rẹ̀ nrú gẹgẹ bi odò wọnni?

8 Egipti dide bi odò Nile, omi rẹ̀ si nrú
bi omi odò wọnni; o si wipe, Emi o goke
lọ, emi o si bò ilẹ aiye, emi o si pa ilu ati
awọn olugbe inu rẹ̀ run!

9 Ẹ goke wá, ẹnyin ẹṣin, ẹ si sare kikan,
ẹnyin kẹkẹ; ki awọn alagbara si jade wá;
awọn ara Etiopia, ati awọn ara Libia, ti o
ndi asà mu; ati awọn ara Lidia ti nmu ti
o nfa ọrun.

10 Ṣugbọn ọjọ yi li ọjọ igbẹsan Oluwa.
Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, ki o le gbẹsan lara
awọn ọta rẹ̀; idà yio si jẹ, yio si tẹ́ ẹ lọrun,
a o si fi ẹ̀jẹ wọn mu u yo: nitori Oluwa,
Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, ni irubọ ni ilẹ
ariwa lẹba odò Ferate.

11 Goke lọ si Gileadi, ki o si mu ikunra,
iwọ wundia, ọmọbirin Egipti: li asan ni
iwọ o lò ọ̀pọlọpọ õgùn; ọja-imularada kò si
fun ọ.

12 Awọn orilẹ-ède ti gbọ́ itiju rẹ, igbe rẹ
si ti kún ilẹ na: nitori alagbara ọkọnrin ti
kọsẹ lara alagbara, ati awọn mejeji si jumọ
ṣubu pọ̀.

13 Ọrọ ti Oluwa sọ fun Jeremiah, woli,
nigbati Nebukadnessari, ọba Babeli wá lati
kọlu ilẹ Egipti.

14 Ẹ sọ ọ ni Egipti, ki ẹ si jẹ ki a gbọ́
ni Migdoli, ẹ si jẹ ki a gbọ́ ni Nofu ati Ta-
fanesi: ẹ wipe, duro lẹsẹsẹ, ki o si mura,
nitori idà njẹrun yi ọ kakiri.

15 Ẽṣe ti a fi gbá awọn akọni rẹ lọ?
nwọn kò duro, nitori Oluwa le wọn.

16 A sọ awọn ti o kọsẹ di pupọ, lõtọ,
ẹnikini ṣubu le ori ẹnikeji: nwọn si wipe,
Dide, ẹ jẹ ki a pada lọ sọdọ awọn enia wa,
ati si ilẹ ti a bi wa, kuro lọwọ idá anini-
lara.

17 Nwọn kigbe nibẹ; Farao, ọba Egipti
ti ṣegbe: on ti kọja akoko ti a dá!

18 Bi emi ti wà, li Ọba, ẹniti orukọ rẹ̀
ijẹ Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, pe, nitõtọ
gẹgẹ bi Tabori lãrin awọn oke, ati gẹgẹ bi
Karmeli lẹba okun, bẹ̃ni on o de.

Digitized by Google

19 Iwọ, ọmọbirin ti ngbe Egipti, pèse
ohun-èlo irin-ajo fun ara rẹ: nitori Nofu
yio di ahoro, a o si fi joná, laini olugbe.
20 Ẹgbọrọ malu ti o dara pupọ ni Egipti,
lõtọ, ìparun de, o de lati ariwa!
21 Awọn ologun rẹ̀ ti a fi owo bẹ̀, dabi
akọmalu abọpa lãrin rẹ; awọn wọnyi pẹlu
yi ẹhin pada; nwọn jumọ sa lọ pọ: nwọn
kò duro, nitoripe ọjọ wàhala wọn de sori
wọn, àkoko ibẹwo wọn.
22 Ohùn inu rẹ̀ yio lọ gẹgẹ bi ti ejo;
nitori nwọn o lọ pẹlu agbara; pẹlu àkeke
lọwọ ni nwọn tọ̀ ọ wá bi awọn akégi.
23 Nwọn o ke igbo rẹ̀ lulẹ, li Oluwa wi,
nitori ti a kò le ridi rẹ̀; nitoripe nwọn pọ̀
jù ẹlẹnga lọ, nwọn si jẹ ainiye.
24 Oju yio tì ọmọbirin Egipti; a o fi i le
ọwọ awọn enia ariwa.
25 Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli,
wipe; Wò o, emi o bẹ̀ Amoni ti No,
ati Farao, ati Egipti wò, pẹlu awọn ọlọla
wọn, ati awọn ọba wọn; ani Farao ati
gbogbo awọn ti o gbẹkẹ le e:
26 Emi o si fi wọn le ọwọ awọn ti nwá
ẹmi wọn, ati le ọwọ Nebukadnessari, ọba
Babeli, ati le ọwọ awọn iranṣẹ rẹ̀: lẹhin
na, a o si mã gbe inu rẹ̀, gẹgẹ bi ìgba atijọ,
li Oluwa wi.
27 Ṣugbọn iwọ má bẹ̀ru, iwọ Jakobu,
ọmọ-ọdọ mi, má si fòya, iwọ Israeli: nitori,
wò o, emi o gbà ọ là lati okere wá, ati
iru-ọmọ rẹ lati ilẹ ìgbekun wọn; Jakobu
yio si pada, yio si wà ni isimi, yio si gbe
jẹ, ẹnikan kì o si dẹ̀ru bà a.
28 Iwọ má bẹ̀ru, iwọ Jakobu, ọmọ-ọdọ
mi, li Oluwa wi: nitori emi wà pẹlu rẹ;
nitori emi o ṣe opin patapata ni gbogbo
awọn orilẹ-ède, nibiti emi ti le ọ si: ṣugbọn
emi kì o ṣe ọ li opin patapata, ṣugbọn
emi o ba ọ wi ni ìwọn; sibẹ emi kì yio jọ̃
rẹ lọwọ li alaijiya.

## ORI 47.

ỌRỌ Oluwa ti o tọ̀ Jeremiah woli wá, si
awọn ara Filistia, ki Farao ki o to
kọlu Gasa.
2 Bayi li Oluwa wi; Wò o, omi dide
lati ariwa, yio si jẹ kikun omi akunya, yio
si ya bo ilẹ na, ati gbogbo ẹkún inu rẹ̀;
ilu na, ati awọn ti ngbe inu rẹ̀: nigbana
ni awọn enia yio kigbe, gbogbo awọn olugbe
ilẹ na yio si hu.
3 Nipa ariwo titẹlẹ patakò ẹṣẹ alagbara
ẹṣin rẹ̀, nipa iró nla kẹ̀kẹ rẹ̀, ati nipa ariwo
nla ayika kẹ̀kẹ̀ rẹ̀; awọn baba kì yio bojuwo
ẹhin wò awọn ọmọ wọn nitori ọwọ́ rirọ;
4 Nitori ọjọ na ti mbọ lati pa gbogbo
awọn ara Filistia run, ati lati ke gbogbo
oluranlọwọ ti o kù kuro lọdọ Tire ati Sidoni:
nitori Oluwa yio ṣe ikogun awọn ara
Filistia, ani iyokù erekuṣu Kaftori.
5 Ipàri de si Gasa, Aṣkeloni ti dahoro,
pẹlu iyokù afonifoji wọn: iwọ o ti ṣa ara
rẹ lọgbẹ pẹ to?
6 Ye! iwọ idà Oluwa, yio ti pẹ to ki
iwọ ki o to gbe jẹ? tẹ ara rẹ bọ inu akọ rẹ,
simi! ki o si dakẹ!
7 Ṣugbọn bawo li o ti ṣe le gbe jẹ, nigbati
Oluwa ti paṣẹ fun u si Aṣkeloni, ati
si ebute okun, nibẹ li o ti ran a lọ!

## ORI 48.

SI Moabu. Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun,
Ọlọrun Israeli, wi; pe, Egbe ni
fun Nebo! nitoriti a fi ṣe ijẹ: oju tì Kiriataimu,
a si kó o: oju tì Misgabu, o si
wariri.
2 Ogo Moabu kò si mọ: nwọn ti gbero
ibi si i ni Heṣboni, pe, wá, ki ẹ si jẹ ki a
ke e kuro lati jẹ orilẹ-ède. A o ke ọ lulẹ
pẹlu iwọ Madmeni; idà yio tẹle ọ.
3 Ohùn igbe lati Horonaimu, iparun ati
idahoro nla!
4 A pa Moabu run; awọn ọmọde rẹ̀ mu
ki a gbọ́ igbe.
5 Nitori ẹkun tẹle ẹkun ni ọ̀na igoke lọ
si Luhiti: nitori ni ọ̀na isọkalẹ Horonaimu
a gbọ́ imi-ẹ̀dun, igbe iparun, pe:
6 Ẹ sa, ẹ gbà ẹmi nyin là, ki ẹ si dabi
alaini li aginju!
7 Njẹ nitoriti iwọ ti gbẹkẹle iṣẹ ọwọ rẹ
ati le iṣura rẹ, a o si kó iwọ pẹlu: Kemoṣi
yio si jumọ lọ si ìgbekun, pẹlu awọn alufa
rẹ̀, ati awọn ijoye rẹ̀.
8 Awọn oluparun yio wá sori olukuluku
ilu, ilu kan kì o si bọ́: afonifoji pẹlu yio
ṣègbe, a o si pa pẹtẹlẹ run, gẹgẹ bi Oluwa
ti wi.
9 Fi iyẹ fun Moabu, ki o ba le fò ki o si
lọ, ilu rẹ̀ yio si di ahoro, laisi ẹnikan lati
gbe inu rẹ̀.
10 Ifibu li ẹniti o ṣe iṣẹ Oluwa ni imẹlẹ,
ifibu si li ẹniti o dá idà rẹ̀ duro kuro ninu
ẹjẹ.
11 Moabu ti wà ni irọra lati igba ewe rẹ̀
wá, o si ti silẹ lori gẹdẹgẹdẹ̀ bi ọti-waini, a
kò si ti dà a lati inu ohun-elo, de ohun-elo
bẽni kò ti ilọ si igbekun: nitorina itọwò
rẹ̀ wà ninu rẹ̀, õrùn rẹ̀ kò si pada.
12 Nitorina, wò o, ọjọ mbọ̀, li Oluwa
wi, ti emi o rán awọn atẹni-sapakan si i, ti



Digitized by Google

o si tẹ̀ ẹ sapakan, nwọn o si sọ gbogbo
ohun-elo rẹ̀ di ofo, nwọn o si fọ ìgo wọn.
13 Moabu yio si tiju nitori Kemoṣi,
gẹgẹ bi ile Israeli ti tiju nitori Beteli,
igbẹkẹle wọn.
14 Ẹnyin ha ṣe wipe, akọni ọkọnrin ni
awa, alagbara fun ogun ?
15 A fi Moabu ṣe ijẹ, ẽfin ilu rẹ̀ si goke
lọ, awọn àṣayan ọdọmọkọnrin rẹ̀ si sure lọ
si ibi pipa, li Ọba wi, ẹniti orukọ rẹ̀ ijẹ,
Oluwa awọn ọmọ-ogun.
16 Wahala Moabu sunmọ tosi lati de,
ipọnju rẹ̀ si nyara kánkan.
17 Gbogbo ẹnyin ti o wà yi i ka, ẹ ke-
daro rẹ̀ ; ati gbogbo ẹnyin ti o mọ̀ orukọ
rẹ̀, ẹ wipe, bawo li ọpa agbara rẹ fi ṣẹ́, ọpa
ogo !
18 Iwọ olugbe ọmọbirin Diboni, sọkalẹ
lati inu ogo, ki o si ma gbe ibi ongbẹ ; ni-
tori afiniṣe-ijẹ. Moabu yio goke wá sori rẹ,
yio si pa ilu olodi rẹ run.
19 Iwọ olugbe Aroeri ! duro lẹba ọ̀na,
ki o si wò ; bère lọwọ ẹniti nsa, ati ẹniti
nsala, wipe, Kili o ṣe ?
20 Oju tì Moabu : nitori a wó o lulẹ : ẹ
hu, ki ẹ si kigbe ; ẹ kede rẹ̀ ni Arnoni pe :
a fi Moabu ṣe ijẹ,
21 Idajọ si ti de sori ilẹ pẹtẹlẹ ; sori
Holoni, ati sori Jahasi, ati sori Mefaati,
22 Ati sori Diboni, ati sori Nebo, ati
sori Bet-diblataimu.
23 Ati sori Kiriataimu, ati sori Bet-
Gamuli, ati sori Bet-Meoni,
24 Ati sori Kerioti, ati sori Bosra, ati
sori gbogbo ilu ilẹ Moabu, lokere ati nitosi.
25 A ke iwo Moabu kuro, a si ṣẹ́ apá rẹ̀,
li Oluwa wi.
26 Ẹ mu u yo bi ọmuti : nitori o gbera-
ra si Oluwa : Moabu yio si ma pàfọ ninu
ẽbi rẹ̀ ; on pẹlu yio si di ẹni-ẹ̀gan.
27 Kò ha ri bẹ̃ pe : Israeli jẹ ẹni ẹlẹyà
fun ọ bi ? bi ẹnipe a ri i lãrin awọn ole ?
nitori ni igbakũgba ti iwọ ba nsọ̀rọ rẹ̀, iwọ
a ma mì ori rẹ.
28 Ẹnyin olugbe Moabu ! ẹ fi ilu wọnni
silẹ, ki ẹ si mã gbe inu apata, ki ẹ si jẹ
gẹgẹ bi oriri ti o kọ́ itẹ rẹ̀ li ẹba ẹnu ihò.
29 Awa ti gbọ́ igberaga Moabu, o gbera-
ga pupọ, iṣefefe rẹ̀, ati afojudi rẹ̀, ati igbe-
raga rẹ̀, ati giga ọkàn rẹ̀.
30 Emi mọ̀ ìwa igberaga rẹ̀ ; li Oluwa
wi : ṣugbọn kò ri bẹ̃ ; ọ̀rọ asan rẹ̀, ti kò le
ṣe nkankan.
31 Nitorina ni emi o hu fun Moabu, emi
o si kigbe soke fun gbogbo Moabu, lori
awọn ọkọnrin Kirheresi li a o ṣọ̀fọ.
32 Emi o sọkun fun àjara Sibma jù
ẹkún Jaseri lọ : ẹka rẹ ti rekọja okun lọ,
nwọn de okun Jaseri : afiniṣe-ijẹ yio kọlu
ikore eso rẹ ati ikore eso-àjara rẹ.
33 Ati ayọ̀ ati ariwo inu-didùn li a mu
kuro li oko, ati kuro ni ilẹ Moabu ; emi si
ti mu ki ọti-waini tán ninu ifunti : ẹnikan
kì o fi ariwo tẹ̀ ọti-waini ; ariwo ikore kì
yio jẹ ariwo ikore mọ.
34 Lati igbe Heṣboni de Eleale, de
Jahasi, ni nwọn fọ ohùn wọn, lati Soari de
Horonaimu, ti iṣe ẹgbọrọ malu ọlọdun mẹ-
ta, nitori omi Nimrimu pẹlu yio dahoro.
35 Emi o si mu ki o dopin ni Moabu, li
Oluwa wi : ẹniti o nrubọ ni ibi giga, ati
ẹniti nsun turari fun oriṣa rẹ̀.
36 Nitorina ni ọkàn mi ró fun Moabu bi
fère, ọkàn mi yio si ró bi fere fun awọn
ọkọnrin Kirheresi: nitori iṣura ti o kojọ
ṣegbe.
37 Nitori gbogbo ori ni yio pá, ati gbo-
gbo irungbọn li a o ke kù : ọgbẹ yio wà ni
gbogbo ọwọ, ati aṣọ-ọ̀fọ ni ẹgbẹ mejeji.
38 Ẹkún nlanla ni yio wà lori gbogbo
orule Moabu, ati ni ita rẹ̀ : nitori emi ti fọ́
Moabu bi ati ifọ́ ohun-elo, ti kò wù ni, li
Oluwa wi.
39 Ẹ hu, pe, bawo li a ti wo o lulẹ ! ba-
wo ni Moabu ti fi itiju yi ẹhin pada ! bẹ̃ni
Moabu yio di ẹ̀gan ati idãmu si gbogbo
awọn ti o yi kakiri.
40 Nitori bayi li Oluwa wi ; Wò o, on
o fò gẹgẹ bi idì, yio si nà iye rẹ̀ lori
Moabu.
41 A kó Kerioti, a si kó awọn ilu olodi,
ati ọkàn awọn akọni Moabu li ọjọ na yio
dabi ọkàn obirin ninu irọbi rẹ̀.
42 A o si pa Moabu run lati má jẹ orilẹ-
ède, nitoripe o ti gberaga si Oluwa.
43 Ẹ̀ru, ati ọ̀fin, ati okùn-didẹ, yio wà
lori rẹ iwọ olugbe Moabu, li Oluwa wi.
44 Ẹniti o ba sa fun ẹ̀ru yio ṣubu sinu
ọ̀fin ; ati ẹniti o ba jade kuro ninu ọ̀fin ni
a o mu ninu okùn-didẹ : nitori emi o mu
wá sori rẹ̀, ani sori Moabu, ọdun ibẹ̀wo
wọn, li Oluwa wi.
45 Awọn ti o sá, duro li aini agbara labẹ
ojiji Heṣboni : ṣugbọn iná yio jade wá lati
Heṣboni, ati ọwọ-iná lati ãrin Sihoni, yio
si jẹ ilẹ Moabu run, ati agbari awọn ọmọ
ahoro.
46 Egbe ni fun ọ, iwọ Moabu ! orilẹ̀-ède
Kemoṣi ṣegbe : nitori a kó awọn ọkọnrin
rẹ ni igbekun, ati awọn ọmọbirin rẹ ni
igbekun.
47 Sibẹ emi o tun mu igbekun Moabu

Digitized by Google

pada li ọjọ ikẹhin, li Oluwa wi. Titi de
ihin ni idajọ Moabu.

## ORI 49.

SI awọn ọmọ Ammoni. Bayi li Oluwa
wi; Israeli kò ha ni awọn ọmọkọnrin?
kò ha ni arole bi? nitori kini Malkomu ṣe
jogun Gadi, ti awọn enia rẹ̀ si joko ni ilu
rẹ̀?
2 Nitorina, wò o, ọjọ mbọ̀, li Oluwa wi,
ti emi o mu ki a gbọ́ idagiri ogun ni Rabba
ti awọn ọmọ Ammoni: yio si di okiti ahoro,
a o si fi iná sun awọn ọmọbirin rẹ̀; ni-
gbana ni Israeli yio jẹ arole awọn ti o ti jẹ
arole rẹ̀, li Oluwa wi.
3 Hu, iwọ Heṣboni; nitori a fi Ai ṣe
ijẹ: kigbe, ẹnyin ọmọbirin Rabba! ẹ di
aṣọ-ọ̀fọ mọra, ẹ pohunrere, ki ẹ si sare
soke-sodo lãrin ọgba! nitori Malkomu yio
jumọ lọ si igbekun, awọn alufa rẹ̀ ati awọn
ijoye rẹ̀.
4 Eṣe ti iwọ fi nṣogo ninu afonifoji,
afonifoji rẹ nṣan lọ, iwọ ọmọbirin ti o gbẹ-
kẹle iṣura rẹ, pe, tani yio tọ̀ mi wá?
5 Wò o, emi o mu ẹ̀ru wá sori rẹ, li
Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun wi, lati ọdọ
gbogbo awọn wọnni ti o wà yi ọ kakiri; a
o si le nyin, olukuluku enia tàra niwaju
rẹ̀; ẹnikan kì o si kó awọn ti nsalọ jọ.
6 Ati nikẹhin emi o tun mu igbekun
awọn ọmọ Ammoni pada, li Oluwa wi.
7 Si Edomu. Bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi; Kò ha si ọgbọ́n mọ ni Temani?
a ha ke imọran kuro lọdọ oloye? ọgbọ́n
wọn ha danu bi?
8 Ẹ sa, ẹ yipada, ẹ ṣe ibi jijin lati ma
gbe ẹnyin olugbe Dedani; nitori emi o mu
wahala Esau wá sori rẹ̀, àkoko ti emi o bẹ̀
ẹ wò.
9 Bi awọn aka-eso ba tọ̀ ọ wá, nwọn kì
o ha kù ẽṣẹ́ eso ajara silẹ? bi awọn ole ba
wá li oru, nwọn kì o ha parun titi yio fi tẹ́
wọn lọrùn.
10 Nitori emi ti tú Esau ni ihoho, emi
ti fi ibi ikọkọ rẹ̀ han, on kì o si le fi ara rẹ̀
pamọ; iru-ọmọ rẹ̀ di ijẹ, ati awọn arakọn-
rin rẹ̀, ati awọn aladugbo rẹ̀, nwọn kò sí
mọ́.
11 Fi awọn ọmọ alainibaba rẹ silẹ, emi
o si pa wọn mọ lãye; ati ki awọn opó rẹ
ki o gbẹkẹle mi.
12 Nitori bayi li Oluwa wi; Wò o,
awọn ẹniti kò jẹbi, lati mu ninu ago, ni
yio mu u lõtọ; iwọ o ha si lọ li alaijiya?
iwọ kì yio lọ li alaijiya, nitori lõtọ iwọ o
mu u.
13 Nitori emi ti fi ara mi bura, li Olu-
wa wi pe; Bosra yio di ahoro, ẹ̀gan, ida-
horo, ati egún; ati gbogbo ilu rẹ̀ ni yio di
ahoro lailai.
14 Ni gbigbọ́ emi ti gbọ́ iró lati ọdọ
Oluwa wá, a si ran ikọ̀ si awọn orilẹ-ède
pe, ẹ kó ara nyin jọ, ẹ wá sori rẹ̀, ẹ si dide
lati jagun.
15 Nitori, wò o, emi o ṣe ọ ni ẹni-kekere
lãrin awọn orilẹ-ède, ẹni-ẹgan lãrin awọn
enia.
16 Ibanilẹ̀ru rẹ ti tan ọ jẹ, igberaga
ọkàn rẹ, nitori iwọ ngbe palapala okuta,
ti o joko li ori oke, bi iwọ tilẹ kọ́ itẹ́ re ga
gẹgẹ bi idì, sibẹ emi o mu ọ sọkalẹ lati ibẹ
wá, li Oluwa wi.
17 Edomu yio si di ahoro: olukuluku
ẹniti o ba rekọja rẹ̀, yio dãmu, yio si rẹrin
si gbogbo ipọnju rẹ̀.
18 Gẹgẹ bi ni ibiṣubu Sodomu ati Go-
morra ati awọn aladugbo rẹ̀, li Oluwa wi;
ẹnikan kì yio gbe ibẹ mọ, bẽni ọmọ enia
kan kì yio ṣatipo ninu rẹ̀.
19 Wò o, yio goke wá bi kiniun lati
igberaga Jordani si ibugbe okuta; nitori
lojiji ni emi o lé wọn jade kuro nibẹ, ati
tani ayanfẹ na ti emi o yàn sori rẹ̀, nitori
tani dabi emi, tani yio si pè mi ṣe ẹlẹri?
ati tani oluṣọ-agutan na, ti yio le duro ni-
waju mi?
20 Nitorina gbọ́ ìmọ Oluwa ti o ti gbà
si Edomu; ati èro rẹ̀ ti o ti gba si awọn
olugbe Temani pe, Lõtọ awọn ẹniti o kere
julọ ninu agbo-ẹran yio wọ́ wọn kiri, lõtọ
nwọn o sọ buka wọn di ahoro lori wọn.
21 Ilẹ o mì nipa ariwo iṣubu wọn, ariwo!
a gbọ́ ohùn igbe rẹ̀ li Okunpupa.
22 Wò o, yio goke wá yio si fò gẹgẹ bi
idì, yio si nà iyẹ rẹ̀ sori Bosra: ati li ọjọ
na ni ọkàn awọn alagbara ọkọnrin Edomu
yio dabi ọkàn obirin ni irọbi.
23 Si Damasku. Oju tì Hamati, ati
Arpadi: nitori nwọn ti gbọ́ ìhin buburu:
aiya ja wọn; idãmu wà lẹba okun; nwọn
kò le ri isimi.
24 Damasku di alailera, o yi ara rẹ̀ pada
lati sa, iwariri si dì i mu: ẹ̀dun ati irora
ti dì i mu, gẹgẹ bi obirin ti nrọbi.
25 Bawo ni a kò ṣe fi ilu iyìn silẹ, ilu
ayọ̀ mi!
26 Nitorina awọn ọdọmọkọnrin rẹ̀ yio
ṣubu ni ita rẹ̀, ati gbogbo awọn ọkọnrin
ogun ni a o ke kuro li ọjọ na, li Oluwa
awọn ọmọ-ogun wi.
27 Emi o si da iná ni odi Damasku, yio
si jo ãfin Benhadadi run.

Digitized by Google

28 Si Kedari, ati si ijọba Hasori, ti
Nebukadnessari ọba Babeli, kó: Bayi li
Oluwa wi; Dide, goke lọ si Kedari, ki ẹ
si pa awọn ọkọnrin ìla-õrùn run.
29 Agọ wọn ati agbo-ẹran wọn ni nwọn
o kó lọ: nwọn o mu aṣọ agọ wọn fun ara
wọn, ati gbogbo ohun-èlo wọn, ati ibakasiẹ
wọn; nwọn o si kigbe sori wọn pe, Ẹ̀ru
yikakiri!
30 Sa, yara salọ, fi ara pamọ si ibi jijìn,
ẹnyin olugbe Hasori, li Oluwa wi; nitori
Nebukadnessari ọba Babeli, ti gbìmọ kan
si nyin, o si ti gba èro kan si nyin.
31 Dide, goke lọ sọdọ orilẹ-ède kan ti o
wà ni irọra, ti o ngbe li ailewu, li Oluwa
wi, ti kò ni ilẹkun ẹnu-bode tabi ikere; ti
ngbe fun ara rẹ̀.
32 Ibaksiẹ wọn yio si di ikogun, ati
ọ̀pọlọpọ ẹran-ọ̀sin wọn yio di ijẹ: emi o si
tú awọn ti nda ọ̀şu ka si gbogbo ọ̀na afẹfẹ;
emi o si mu wahala wọn de lati iha gbogbo,
li Oluwa wi.
33 Hasori yio di ibugbe fun ọ̀wawa,
ahoro titi lai: kì o si ẹnikan ti yio joko
nibẹ, bẽni ọmọ enia kan kì yio şatipo ninu
rẹ̀.
34 Ọ̀rọ Oluwa ti o tọ Jeremiah, woli,
wá si Elamu, ni ibẹrẹ ijọba Sedekiah, ọba
Juda, wipe:
35 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi;
Wò o, emi o şẹ́ ọrun Elamu, ti işe olori
agbara wọn.
36 Ati sori Elamu ni emi o mu afẹfẹ
mẹrin lati igun mẹrẹrin ọrun wá, emi o si
tú wọn ka si gbogbo ọ̀na afẹfẹ wọnni, kì o
si sí orilẹ-ède kan, nibiti awọn ãsá Elamu
kì yio de.
37 Nitori emi o mu Elamu warìri niwaju
awọn ọta wọn, ati niwaju awọn ti nwá ẹmi
wọn: emi o si mu ibi wá sori wọn, ani ibi-
nu gbigbona mi, li Oluwa wi; emi o si
rán idà tẹle wọn, titi emi o fi run wọn.
38 Emi o si gbe itẹ mi kalẹ ni Elamu,
emi o si pa ọba ati awọn ijoye run kuro
nibẹ, li Oluwa wi.
39 Şugbọn yio si şe, ni ikẹhin ọjọ, emi
o tun mu igbèkun Elamu pada, li Oluwa
wi.

## ORI 50.

Ọ̀RỌ ti Oluwa sọ si Babeli ati si ilẹ awọn
ara Kaldea nipa ẹnu Jeremiah woli.
2 Ẹ sọ ọ lãrin awọn orilẹ-ède, ẹ si kede,
ki ẹ si gbe asia soke: ẹ kede, ẹ má si şe
bò o: wipe, a kó Babeli, oju tì Beli, a fọ
Merodaki tutu; oju tì awọn ere rẹ̀, a fọ
awọn òrişa rẹ̀ tutu.
3 Nitori lati ariwa ni orilẹ-ède kan ti
wá sori rẹ̀, ti yio sọ ilẹ rẹ̀ di ahoro, ẹnikan
kì o gbe inu rẹ̀; nwọn o sa, nwọn o lọ, ati
enia ati ẹranko.
4 Li ọjọ wọnni ati li àkoko na, li Oluwa
wi, awọn ọmọ Israeli yio jumọ wá, awọn,
ati awọn ọmọ Juda, nwọn o ma lọ tẹkúntẹ-
kún: nwọn o lọ, nwọn o si şafẹri Oluwa
Ọlọrun wọn.
5 Nwọn o ma bère ọ̀na Sioni, oju wọn
yio si yi sibẹ, nwọn o wá, nwọn o darapọ
mọ Oluwa ni majẹmu aiye-raiye, ti a kì
yio gbagbe.
6 Awọn enia mi ti jẹ́ agbo-agutan ti o
sọnu: awọn oluşọ-agutan wọn ti jẹ ki
nwọn şina, nwọn ti jẹ ki nwọn rìn kiri lori
oke: nwọn ti lọ lati ori oke nla de oke
kekere, nwọn ti gbagbe ibusun wọn.
7 Gbogbo awọn ti o ri wọn, ti pa wọn
jẹ: awọn ọta wọn si wipe, Awa kò jẹbi,
nitoripe nwọn ti şẹ̀ si Oluwa, ibugbe ododo,
ati ireti awọn baba wọn, ani Oluwa.
8 Ẹ salọ kuro li ãrin Babeli, ẹ si jade
kuro ni ilẹ awọn ara Kaldea, ki ẹ si jẹ bi
obukọ niwaju agbo-ẹran.
9 Nitori, wò o, emi o gbe dide, emi o si
mu apejọ awọn orilẹ-ède nla lati ilẹ ariwa
wá sori Babeli: nwọn o si tẹgun si i, lati
ibẹ wá li a o si ti mu u: ọfa wọn yio dabi
ti akọni amoye; ọkan kì yio pada li asan.
10 Kaldea yio si di ikogun: gbogbo
awọn ti o fi şe ikogun ni a o tẹ́ lọrùn, li
Oluwa wi.
11 Nitoripe inu nyin dùn, nitoripe ẹnyin
yọ̀, ẹnyin olè ti o ji ini mi, nitori ti ẹnyin
fi ayọ̀ fò bi ẹgbọrọ malu si koriko tutu, ẹ si
nyan bi akọ-ẹşin:
12 Oju yio tì iya nyin pupọpupọ; itiju
yio bo ẹniti o bi nyin: wò o, ikẹhin awọn
orilẹ-ède! aginju, ilẹ gbigbẹ, ati ahoro!
13 Nitori ibinu Oluwa li a kì yio gbe
inu rẹ̀, şugbọn yio dahoro patapata: olu-
kuluku ẹniti o ba re Babeli kọja yio yanu,
yio si şe ẹlẹya si gbogbo ipọnju rẹ̀.
14 Ẹ tẹgun si Babeli yikakiri: gbogbo
ẹnyin ti nfà ọrun, ẹ tafa si i, ẹ máşe şún
ọfa lò, nitoriti o ti şẹ̀ si Oluwa.
15 Ẹ ho bò o yikakiri: o ti nà ọwọ rẹ̀:
ọwọ̀n ìti rẹ̀ şubu, a wó odi rẹ̀ lulẹ: nitori
igbẹsan Oluwa ni: ẹ gbẹsan lara rẹ̀: gẹgẹ
bi o ti şe, ẹ şe bẽ si i.
16 Ke afunrugbin kuro ni Babeli, ati
ẹniti ndi doje mu ni igba ikore! nitori ẹ̀ru
idà ti nşika, olukuluku wọn o yipada si

Digitized by Google

ọdọ enia rẹ̀, olukuluku yio si salọ si ilẹ rẹ̀.

17 Israeli jẹ́ agutan ti o ṣina kiri, awọn kiniun ti le e lọ: niṣaju ọba Assiria pa a jẹ, ati nikẹhin yi Nebukadnessari, ọba Babeli, sán egungun rẹ̀.

18 Nitorina bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, wi, pe, wò o, emi o jẹ ọba Babeli ati ilẹ rẹ̀ niyà, gẹgẹ bi emi ti jẹ ọba Assiria niya.

19 Emi o si tun mu Israeli wá si ibugbe rẹ̀, on o si ma bọ ara rẹ̀ lori Karmeli, ati Baṣani, a o si tẹ́ ọkàn rẹ̀ lọrun li oke Efraimu ati ni Gileadi.

20 Li ọjọ wọnni, ati li akoko na, li Oluwa wi, a o wá aiṣedẽde Israeli kiri, ṣugbọn kì o si mọ́; ati ẹ̀ṣẹ Juda, a kì o si ri wọn: nitori emi o dariji awọn ti mo mu ṣẹkù.

21 Goke lọ si ilẹ ọlọtẹ li ọ̀na meji, ani sori rẹ̀ ati si awọn olugbe ilu Ibẹwo: sọ ọ di ahoro ki o si parun lẹhin wọn, li Oluwa wi, ki o si ṣe gẹgẹ bi gbogbo eyiti emi ti paṣẹ fun ọ.

22 Iró ogun ni ilẹ na, ati ti iparun nla!

23 Bawo li a ti fọ, ti a si ṣẹ olú gbogbo ilẹ aiye! Bawo ni Babeli di ahoro lãrin awọn orilẹ-ède!

24 Emi ti kẹ okùn fun ọ, a si mu ọ, iwọ Babeli, iwọ kò si mọ̀: a ri ọ, a si mu ọ pẹlu, nitoripe iwọ ti ba Oluwa ja.

25 Oluwa ti ṣi ile ohun-ijà rẹ̀ silẹ: o si ti mu ohun-elo ikannu rẹ̀ jade: nitori Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, ni iṣẹ iṣe ni ilẹ awọn ara Kaldea.

26 Ẹ wá sori rẹ̀ lati opin gbogbo, ṣi ile iṣura rẹ̀ silẹ: ẹ kó o jọ bi òkiti, ki ẹ si yà a sọtọ fun iparun, ẹ máṣe fi iyokù silẹ fun u!

27 Pa gbogbo awọn akọ-malu rẹ̀! nwọn o lọ si ibi pipa: ègbe ni fun wọn! nitori ọjọ wọn de, àkoko ibẹwo wọn.

28 Ohùn awọn ti o salọ, ti o si sala lati ilẹ Babeli wá, lati kede igbẹsan Oluwa Ọlọrun wa ni Sioni, igbẹsan tempili rẹ̀!

29 Pè ọ̀pọlọpọ enia, ani gbogbo tafatafa, sori Babeli, ẹ dótì i yikakiri; má jẹ ki ẹnikan sala: san fun u gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀; gẹgẹ bi gbogbo eyi ti o ti ṣe, ẹ ṣe bẽ si i, nitoriti o ti gberaga si Oluwa, si Ẹni-Mimọ Israeli.

30 Nitorina ni awọn ọdọmọdekọnrin rẹ̀ yio ṣubu ni ita rẹ̀, ati gbogbo awọn ologun rẹ̀ li a o ke kuro li ọjọ na, li Oluwa wi.

31 Wò o, emi dojukọ ọ! iwọ agberaga, li Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, wi: nitori ọjọ rẹ de, àkoko ti emi o bẹ̀ ọ wò.

32 Agberaga yio kọsẹ, yio si ṣubu, ẹnikan kì o si gbe e dide: emi o si da iná ni ilu rẹ̀, yio si jo gbogbo ohun ti o yi i kakiri.

33 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, pe, awọn ọmọ Israeli ati awọn omọ Juda li a jumọ pọn loju pọ̀: gbogbo awọn ti o kó wọn ni ìgbekun si di wọn mu ṣinṣin; nwọn kọ̀ lati jọ wọn lọwọ lọ.

34 Ṣugbọn Olurapada wọn lagbara; Oluwa awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀: ni jijà yio gba ijà wọn jà! ki o le mu ilẹ na simi, ki o si mu awọn olugbe Babeli wariri.

35 Ida lori awọn ara Kaldea, li Oluwa wi, ati lori awọn olugbe Babeli, ati lori awọn ijoye rẹ̀, ati lori awọn ọlọgbọn rẹ̀!

36 Idà lori awọn ahalẹ! nwọn o si ṣarán: idà lori awọn alagbara rẹ̀; nwọn o si damu.

37 Idà lori awọn ẹṣin rẹ̀, ati lori awọn kẹ̀kẹ ati lori gbogbo awọn àjeji enia ti o wà lãrin rẹ̀; nwọn o si di obirin: idà lori iṣura rẹ̀; a o si kó wọn lọ.

38 Ọda lori omi odò rẹ̀; nwọn o si gbẹ: nitori ilẹ ere fifin ni, nwọn si nṣogo ninu oriṣa wọn.

39 Nitorina awọn ẹran-iju pẹlu ọ̀wawa ni yio ma gbe ibẹ̀, abo ògongo yio si ma gbe inu rẹ̀, a kì o si gbe inu rẹ̀ mọ lailai; bẽni a kì o ṣatipo ninu rẹ̀ lati irandiran:

40 Gẹgẹ bi Ọlọrun ti bì Sodomu ati Gomorra ṣubu ati awọn aladugbo rẹ̀, li Oluwa wi; bẽni enia kan kì o gbe ibẹ, tabi ọmọ enia kan kì o ṣatipo ninu rẹ̀.

41 Wò o, orilẹ-ède kan yio wá lati ariwa, ati orilẹ-èdẹ nla, ọba pupọ li o si dide lati opin ilẹ aiye wá.

42 Nwọn o di ọrun ati ọ̀kọ mu: onroro ni nwọn, nwọn kì o si ṣe ãnu: ohùn wọn yio ho gẹgẹ bi okun, nwọn o si gun ori ẹṣin lẹsẹsẹ, nwọn si mura bi ọkọnrin ti yio jà ọ logun, iwọ ọmọbirin Babeli.

43 Ọba Babeli ti gbọ́ iró wọn, ọwọ rẹ̀ si rọ: ẹ̀dun dì i mu, ati irora gẹgẹ bi obirin ti nrọbi.

44 Wò o, on o goke wá bi kiniun lati wiwú Jordani si ibugbe okuta; nitori ojiji li emi o le wọn lọ kuro nibẹ; ati tani si li ẹniti a yàn, ti emi o yàn sori rẹ̀? nitori tani dabi emi? tani o si pè mi ṣe ẹlẹri? ati tani oluṣọ-agutan na ti yio le duro niwaju mi?

45 Nitorina gbọ́ ìmọ Oluwa, ti o ti gba si Babeli: ati èro rẹ̀, ti o ti gba si ilẹ awọn ara Kaldea: lõtọ awọn ti o kere julọ ninu agbo-ẹran: yio wọ́ wọn kiri: lõtọ on o sọ ibugbe di ahoro lori wọn.

46 Nitori ohùn igbe nla pe: a kó Babeli,

Digitized by Google

ilẹ-aiye mì, a si gbọ́ ariwo na lãrin awọn orilẹ-ède.

## ORI 51.

BAYI li Oluwa wi: wò o, emi o rú afẹfẹ iparun soke si Babeli, ati si awọn ti ngbe ãrin awọn ti o dide si mi;

2 Emi o si rán awọn alatẹ si Babeli, ti yio fẹ ẹ, nwọn o si sọ ilẹ rẹ̀ di ofo: nitori li ọjọ wahala ni nwọn o wà lọdọ rẹ̀ yikakiri.

3 Jẹ ki tafatafa fà ọrun rẹ̀ si ẹniti nfà ọrun, ati si ẹniti o nṣogo ninu ẹ̀wu irin rẹ̀: ẹ má si ṣe dá awọn ọdọmọde-kọnrin rẹ̀ si, ẹ run gbogbo ogun rẹ̀ patapata.

4 Awọn ti a pa yio si ṣubu ni ilẹ awọn ara Kaldea, awọn ti a gún li ọ̀kọ, yio si ṣubu ni ita rẹ̀.

5 Nitori Israeli ati Juda, kì iṣe opó niwaju Ọlọrun wọn, niwaju Oluwa, awọn ọmọ-ogun; nitori ilẹ wọn (Babeli) ti kún fun ẹbi si Ẹni-Mimọ Israeli.

6 Ẹ salọ kuro lãrin Babeli, ki olukuluku enia ki o si gbà ọkàn rẹ̀ là: ki a máṣe ke nyin kuru ninu aiṣedede rẹ̀; nitori eyi li àkoko igbẹsan fun Oluwa; yio san ère iṣẹ fun u.

7 Babeli jẹ ago wura lọwọ Oluwa, ti o mu gbogbo ilẹ aiye yo bi ọ̀muti: awọn orilẹ-ède ti mu ninu ọti-waini rẹ̀; nitorina ni awọn orilẹ-ède nṣogo.

8 Babeli ṣubu, a si fọ ọ lojiji: ẹ hu fun u; ẹ mu ikunra fun irora rẹ̀, bi o jẹ bẽ pe, yio san fun u.

9 Awa fẹ wò Babeli sàn, ṣugbọn kò sàn; ẹ kọ̀ ọ silẹ, ki ẹ si jẹ ki a lọ, olukuluku si ilẹ rẹ̀: nitori ẹbi rẹ̀ de ọrun, a si gbe e soke de awọsanma.

10 Oluwa mu ododo wa jade; ẹ wá, ẹ jẹ ki a si kede iṣẹ Oluwa Ọlọrun wa ni Sioni.

11 Pọ́n ọfa mu: mu asà li ọwọ: Oluwa ti rú ẹmi awọn ọba Media soke: nitori ipinnu rẹ̀ si Babeli ni lati pa a run, nitoripe igbẹsan Oluwa ni, igbẹsan fun tempili rẹ̀.

12 Gbé asia soke lori odi Babeli, mu awọn iṣọ lagbara, mu awọn oluṣọ duro, ẹ yàn ẹ̀bu: nitori Oluwa gbero, o si ṣe eyi ti o wi si awọn olugbe Babeli.

13 Iwọ ẹniti ngbe ẹba omi pupọ, ti o pọ̀ ni iṣura, opin rẹ de, iwọn ikogun-ole rẹ kún.

14 Oluwa awọn ọmọ-ogun ti fi ẹmi rẹ̀ bura pe, ni kikún emi o fi enia kún ọ gẹgẹ bi ẹlẹnga; nwọn o si pa ariwo ogun lori rẹ.

15 On ti da aiye nipa agbara rẹ̀, on ti ṣe ipinnu araiye nipa ọgbọ́n rẹ̀, o si tẹ́ awọn ọrun nipa oye rẹ̀.

16 Nigbati o ba san ãrá, ọ̀pọlọpọ omi ni mbẹ li oju ọrun; o si mu kũku goke lati opin aiye wá, o dá manamana fun òjo, o si mu ẹfũfu jade lati inu iṣura rẹ̀ wá.

17 Aṣiwere ni gbogbo enia, nitori oye kò si; oju tì gbogbo alagbẹdẹ nitori ere, nitori ere didà rẹ̀ eke ni, kò si sí ẹmi ninu wọn.

18 Asan ni nwọn, ati iṣẹ iṣina: ni ìgba ibẹ̀wo wọn, nwọn o ṣegbe.

19 Ipin Jakobu kò dabi wọn: nitori on ni iṣe Ẹlẹda ohun gbogbo: Israeli si ni ẹ̀ya ijogun rẹ̀: Oluwa awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀.

20 Iwọ ni òlù mi, ohun elo-ogun: emi o fi ọ fọ awọn orilẹ-ède tũtu, emi o si fi ọ pa awọn ijọba run;

21 Emi o si fi ọ fọ ẹṣin ati ẹlẹṣin tũtu; emi o si fi ọ fọ kẹ̀kẹ ati ẹniti o gùn u tũtu;

22 Emi o si fi ọ fọ ọkọnrin ati obirin tũtu; emi o si fi ọ fọ arugbo ati ọmọde tũtu; emi o si fi ọ fọ ọdọmọkọnrin ati wundia tũtu;

23 Emi o si fi ọ fọ oluṣọ-agutan ati agboẹran rẹ̀ tũtu, emi o si fi ọ fọ àgbẹ ati àjagamalu rẹ̀ tũtu; emi o si fi ọ fọ awọn balẹ ati awọn ijoye tũtu.

24 Ṣugbọn emi o si san fun Babeli ati fun gbogbo awọn olugbe Kaldea gbogbo ibi wọn, ti nwọn ti ṣe ni Sioni li oju nyin, li Oluwa wi.

25 Wo o, emi dojukọ ọ, iwọ oke iparun! li Oluwa wi, ti o pa gbogbo ilẹ aiye run; emi o si nà ọwọ mi sori rẹ, emi o si yi ọ lulẹ lati ori apata wá, emi o si ṣe ọ ni oke jijona.

26 Ki nwọn ki o má le mu okuta igun ile, tabi okuta ipilẹ ninu rẹ, ṣugbọn iwọ o di ahoro lailai, li Oluwa wi.

27 Ẹ gbe asia soke ni ilẹ na, fọn ipè lãrin awọn orilẹ-ède, sọ awọn orilẹ-ède di mimọ́ sori rẹ̀, pè awọn ijọba Ararati, Minni, ati Aṣkinasi sori rẹ̀, yàn balogun sori rẹ̀, mu awọn ẹṣin wá gẹgẹ bi ẹlẹnga ẹlẹgun.

28 Sọ awọn orilẹ-ède pẹlu awọn ọba Media di mimọ́ sori rẹ̀, awọn balẹ rẹ̀, ati gbogbo awọn ijoye rẹ̀, ati gbogbo ilẹ ijọba rẹ̀.

29 Ilẹ yio si mì, yio si kerora: nitori gbogbo èro Oluwa li a o muṣẹ si Babeli, lati sọ ilẹ Babeli di ahoro laini olugbe.

30 Awọn akọni Babeli ti dẹkun jijà, nwọn ti joko ninu ile-odi wọn; agbara wọn ti tán; nwọn di obirin, nwọn tinabọ ibugbe rẹ̀; a ṣẹ́ ikere rẹ̀.

Digitized by Google

31 Ẹnikan ti nsare yio sare lọ lati pade
ẹnikeji ti nsare, ati onṣẹ kan lati pade onṣẹ
miran, lati jiṣẹ fun ọba Babeli pe: a kó
ilu rẹ̀ ni iha gbogbo.
32 Ati pe, a gbà awọn asọda wọnni, nwọn
si ti fi ifefe joná, ẹ̀ru si ba awọn ọkọnrin
ogun.
33 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ọgun,
Ọlọrun Israeli, wi, pe, Ọmọbirin Babeli
dábi ilẹ ipaka, li akoko ti a o pa ọka lori
rẹ̀: sibẹ ni igba diẹ si i, akoko ikore rẹ̀
mbọ fun u.
34 Nebukadnessari, ọba Babeli, ti jẹ mi
run, o ti tẹ̀ mi mọlẹ, o ti ṣe mi ni ohun-elo
ofo, o ti gbe mi mì gẹgẹ bi ọ̀wawa, o ti fi
ohun didara mi kún ikun rẹ̀, o ti le mi
jade.
35 Ki ìwa-ika ti a hù si mi ati ẹran-ara
mi ki o wá sori Babeli, bẹ̃ni iwọ olugbe
Sioni yio wi; ati ẹ̀jẹ mi lori awọn olugbe,
ara Kaldea, bẹ̃ni iwọ, Jerusalemu, yio wi.
36 Nitorina bayi li Oluwa wi; Wò o,
emi o gba ijà rẹ jà, emi o si gba ẹsan rẹ,
emi o si gbẹ okun rẹ̀, emi o si mu gbogbo
orisun rẹ̀ gbẹ.
37 Babeli yio si di òkiti àlapa, ibugbe
ọ̀wawa, iyanu, ẹsin, laini olugbe.
38 Nwọn o jumọ bú bi kiniun: nwọn o
si ke bi ọmọ kiniun.
39 Ninu oru wọn li emi o ṣe ase ohun
mimu fun wọn, emi o si mu wọn yo bi
ọ̀muti, ki nwọn ki o le ma yọ̀, ki nwọn ki
o si sun orun lailai, ki nwọn ki o má si jí
mọ́, li Oluwa wi.
40 Emi o si mu wọn wá bi ọdọ-agutan
si ibi pipa, bi àgbo pẹlu obukọ.
41 Bawo li a kó Ṣeṣaki! bawo li ọwọ
wọn ṣe tẹ iyìn gbogbo ilẹ aiye! bawo ni
Babeli ṣe di iyanu lãrin awọn orilẹ-ède!
42 Okun wá sori Babeli: a si fi ọ̀pọlọpọ
riru omi rẹ̀ bò o mọlẹ.
43 Ilu rẹ̀ ni ahoro, ilẹ gbigbẹ, ati aginju:
ilẹ ninu eyiti ẹnikẹni kò gbe, bẹ̃ni ọmọ enia
kò kọja nibẹ.
44 Nitori emi o jẹ Beli niya ni Babeli,
emi o si mu eyiti o ti gbemì jade li ẹnu rẹ̀:
awọn orilẹ-ède kì yio jumọ ṣàn lọ pọ si ọdọ
rẹ̀ mọ: lõtọ odi Babeli yio wó.
45 Enia mi, ẹ jade li ãrin rẹ̀, ki oluku-
luku nyin si gba ẹmi rẹ̀ là kuro ninu ibinu
gbigbona Oluwa!
46 Ati ki ọkàn nyin má ba rẹ̀wẹsi, ati ki
ẹ má ba bẹ̀ru, nitori iró ti a o gbọ́ ni ilẹ
na; nitori iró na yio de li ọdun na, ati
lẹhin na iró yio de li ọdun keji, ati ìwa-ika
ni ilẹ na, alakoso yio dide si alakoso.
47 Nitorina, wò o, ọjọ mbọ̀, ti emi o bẹ
awọn ere fifin Babeli wò: oju yio si tì gbo-
gbo ilẹ rẹ̀, gbogbo awọn olupa rẹ̀ yio si
ṣubu li ãrin rẹ̀.
48 Ọrun ati aiye, ati gbogbo ohun ti o
wà ninu wọn, yio si kọrin lori Babeli: ni-
tori awọn afiniṣeijẹ yio wá sori rẹ̀ lati
ariwa, li Oluwa wi.
49 Gẹgẹ bi Babeli ti mu ki awọn olupa
Israeli ṣubu, bẹ̃ gẹgẹ li awọn olupa gbogbo
ilẹ aiye yio ṣubu.
50 Ẹnyin ti o ti bọ lọwọ idà, ẹ lọ, ẹ má
duro: ẹ ranti Oluwa li okere, ẹ si jẹ ki
Jerusalemu wá si ọkàn nyin.
51 Oju tì wa, nitoripe awa ti gbọ́ ẹ̀gan:
itiju ti bò wa loju, nitori awọn alejo wá
sori ohun mimọ́ ile Oluwa.
52 Nitorina, wò o, ọjọ mbọ̀, li Oluwa
wi, ti emi o ṣe ibẹwo lori awọn ere fifin rẹ̀:
ati awọn ti o gbọgbẹ yio si mã gbin ja gbo-
gbo ilẹ rẹ̀.
53 Bi Babeli tilẹ goke lọ si ọrun, bi o si
ṣe olodi li oke agbara rẹ̀, sibẹ awọn afini-
ṣeijẹ yio ti ọdọ mi tọ̀ ọ wá, li Oluwa wi.
54 Iró igbe lati Babeli! ati iparun nla
lati ilẹ awọn ara Kaldea!
55 Nitoripe Oluwa ti ṣe Babeli ni ijẹ, o
si ti pa ohùn nla run kuro ninu rẹ̀; riru
wọn si nho bi omi pupọ, a gbọ́ ariwo ohùn
wọn.
56 Nitoripe afiniṣeijẹ de sori rẹ̀, ani sori
Babeli; a mu awọn akọni rẹ̀, a ṣẹ́ gbogbo
ọrun wọn: nitori Ọlọrun ẹsan ni Oluwa,
yio san a nitõtọ.
57 Emi o si mu ki awọn ijoye rẹ̀ yo bi
ọ̀muti, ati awọn ọlọgbọn rẹ̀, awọn bãlẹ rẹ̀,
ati awọn alakoso rẹ̀, ati awọn akọni rẹ̀,
nwọn o si sun orun lailai, nwọn kì o si ji
mọ́, li Ọba wi, ẹniti orukọ rẹ̀ ijẹ Oluwa
awọn ọmọ-ogun.
58 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi:
odi Babeli gbigboro li a o wó lulẹ patapata,
ẹnu-bode giga rẹ̀ li a o si fi iná sun: tobẹ̃
ti awọn enia ti ṣiṣẹ lasan, ati awọn orilẹ-
ède ti ṣiṣẹ fun iná, ti ãrẹ si mu wọn.
59 Ọ̀rọ ti Jeremiah woli paṣẹ fun Seraiah,
ọmọ Neriah, ọmọ Maaseiah, nigbati o nlọ
niti Sedekiah, ọba Judah, si Babeli li ọdun
kẹrin ijọba rẹ̀. Seraiah yi si ni ijoye ibudo.
60 Jeremiah si kọ gbogbo ọ̀rọ-ibi ti yio
wá sori Babeli sinu iwe kan, ani gbogbọ
ọ̀rọ wọnyi ti a kọ si Babeli.
61 Jeremiah si sọ fun Seraiah pe, nigbati
iwọ ba de Babeli, ki iwọ ki o si wò, ki iwọ
ki o si kà gbogbo ọ̀rọ wọnyi.
62 Ki iwọ ki o si wipe, Oluwa, iwọ ti

Digitized by Google

ṣọ̀rọ si ibi yi, lati ke e kuro, ki ẹnikẹni má
ṣe gbe inu rẹ̀, ati enia ati ẹran, nitori pe
yio di ahoro lailai.
63 Yio si ṣe nigbati iwọ ba pari kikà iwe
yi tan, ki iwọ ki o di okuta mọ ọ, ki o si
sọ ọ si ãrin odò Ferate:
64 Ki iwọ si wipe, Bayi ni Babeli yio
rì, kì o si tun dide kuro ninu ibi ti emi o
mu wá sori rẹ̀: ãrẹ̀ yio si mu wọn. Titi
de ìhin li ọ̀rọ Jeremiah.

## ORI 52.

SEDEKIAH jẹ ẹni ọdun mọkanle-logun
nigbati o bẹrẹ si ijọba, o si jọba, ọdun
mọkanla ni Jerusalemu. Orukọ iya rẹ̀ si
ni Hamutali, ọmọbirin Jeremiah, ara
Libna.
2 On si ṣe buburu niwaju Oluwa, gẹgẹ
bi gbogbo eyiti Jehoiakimu ti ṣe.
3 Nitori ibinu Oluwa, o ri bẹ̃ ni Jerusa-
lemu ati Juda, titi o fi tì wọn jade kuro
niwaju rẹ̀. Sedekiah si ṣọtẹ si ọba Babeli.
4 O si ṣe li ọdun kẹsan ijọba rẹ̀, li oṣu
kẹwa, li ọjọ kẹwa oṣu, Nebukadnessari, ọba
Babeli, de, on ati gbogbo ogun rẹ̀ si Jeru-
salemu, o si dó tì i, o si mọdi tì i yikakiri.
5 A si há ilu na mọ titi di ọdun ikọkan-
la Sedekiah ọba.
6 Ati li oṣu kẹrin li ọjọ kẹsan oṣu, ìyan
mu gidigidi ni ilu, tobẹ̃ ti kò si onjẹ fun
awọn enia ilẹ na.
7 Nigbana ni a fọ ilu, gbogbo awọn olo-
gun si sá, nwọn si jade ni ilu li oru, nwọn
gba ọ̀na ẹnu ibode ãrin odi meji, ti o wà li
ẹba ọgbà ọba, ṣugbọn awọn ara Kaldea yi
ilu ka; nwọn si jade lọ li ọ̀na pẹtẹlẹ.
8 Ṣugbọn ogun awọn ara Kaldea lepa
ọba, nwọn si ba Sedekiah ni pẹtẹlẹ Jeriko,
gbogbo ogun rẹ̀ si tuka kurò lọdọ rẹ̀.
9 Nwọn si mu ọba, nwọn si mu u goke
wá si ọdọ ọba Babeli ni Ribla, ni ilẹ Hama-
ti; o si sọ̀rọ idajọ lori rẹ̀.
10 Ọba Babeli si pa awọn ọmọ Sedekiah
niwaju rẹ̀: o pa gbogbo awọn ọlọla Juda
pẹlu ni Ribla.
11 Pẹlupẹlu ọba Babeli fọ Sedekiah li
oju; o si fi ẹ̀wọn dè e, o si mu u lọ si Ba-
beli, o si fi sinu tubu titi di ọjọ ikú rẹ̀.
12 Njẹ li oṣu karun, li ọjọ kẹwa oṣu, ti
o jẹ ọdun kọkandilogun Nebukadnessari,
ọba Babeli, ni Nebusaradani, balogun iṣọ,
ti o nsin ọba Babeli, wá si Jerusalemu.
13 O si kun ile Oluwa, ati ile ọba; ati
gbogbo ile Jerusalemu, ati gbogbo ile nla
li o fi iná sun.
14 Ati gbogbo ogun awọn ara Kaldea, ti
nwọn wà pẹlu balogun iṣọ, wó gbogbo odi
Jerusalemu lulẹ yikakiri.
15 Nebusaradani, balogun isọ, si kó ninu
awọn talaka awọn enia, ati iyokù awọn
enia ti o kù ni ilu, ni igbekun lọ si Babeli,
pẹlu awọn ti o ya lọ, ti o si ya tọ̀ ọba Ba-
beli lọ, ati iyokù awọn ọ̀pọ enia na.
16 Nebusaradani, balogun iṣọ, si fi ninu
awọn talaka ilẹ na silẹ lati mã ṣe alabojuto
ajara ati lati ma ṣe alaroko.
17 Ati ọwọ̀n idẹ wọnni ti mbẹ lẹba ile
Oluwa, ati ijoko wọnni ati agbada idẹ nla
ti o wà ni ile Oluwa ni awọn ara Kaldea fọ
tũtu, nwọn si kó gbogbo idẹ wọn lọ si
Babeli.
18 Ati ìkoko wọnni, ati ọkọ́ wọnni, ati
alumagaji fitila wọnni, ati ọpọ́n wọnni, ati
ṣibi wọnni, ati gbogbo ohun-elo idẹ wọnni
ti nwọn fi nṣiṣẹ isin, ni nwọn kó lọ.
19 Ati awo-koto wọnni, ati ohun ifọnna
wọnni, ati ọpọ́n wọnni, ali ìkoko wọnni,
ati ọpa fitila wọnni, ati ṣibi wọnni, ati ago
wọnni, eyiti iṣe ti wura, wura, ati eyiti iṣe
ti fadaka, fadaka, ni balogun iṣọ kó lọ.
20 Awọn ọwọ̀n meji, agbada nla kan, ati
awọn malu idẹ mejila ti o wà labẹ ijoko, ti
Solomoni ọba, ti ṣe fun ile Oluwa: idẹ gbo-
gbo ohun-elo wọnyi alaini iwọ̀n ni.
21 Ati ọwọ̀n mejeji, giga ọwọ̀n kan ni
igbọnwọ mejidilogun: okùn igbọnwọ me-
jila si yi i ka; ninipọn wọn si jẹ ika mẹrin,
nwọn ni iho ninu.
22 Ati ọna-ori idẹ wà lori rẹ̀; giga ọna-
ori kan si ni igbọnwọ marun, pẹlu iṣẹ
wiwun ati pomegranate lara ọna ori wọnni
yikakiri, gbogbo rẹ̀ jẹ ti idẹ: gẹgẹ bi
wọnyi ni ọ̀wọn ekeji pẹlu, ati pomegranate
rẹ̀.
23 Pomegranate mẹrindilọgọrun li o wà
ni gbangba: gbogbo pomegranate lori iṣẹ
wiwun na jẹ ọgọrun yikakiri.
24 Balogun iṣọ si mu Seraiah, olori ninu
awọn alufa, ati Sefaniah, alufa keji, ati
awọn olusọ iloro mẹta:
25 Ati lati inu ilu o mu iwẹfa kan, ti o
ni itọju awọn ologun; ati awọn ọkọnrin
meje ti nwọn nduro niwaju ọba, ti a ri ni
ilu na; ati akọwe olori ogun ẹniti ntò
awọn enia ilẹ na; ati ọgọta enia ninu
awọn enia ilẹ na, ti a ri li ãrin ilu na.
26 Nebusaradani, balogun iṣọ, si mu
wọn, o si mu wọn tọ̀ ọba Babeli wá si
Ribla.
27 Ọba Babeli si kọlu wọn, o si pa wọn
ni Ribla ni ilẹ Hamati. Bẹ̃li a mu Juda
kuro ni ilẹ rẹ̀.

Digitized by Google

28 Eyi li awọn enia ti Nebukadnessari
kó ni igbekun lọ: li ọdun keje, ẹgbẹdogun
o le mẹtalelogun ara Juda.
29 Li ọdun kejidilogun Nebukadnessari,
o kó ẹgbẹrin enia o le mejilelọgbọn ni igbè-
kun lati Jerusalemu lọ:
30 Li ọdun kẹtalelogun Nebukadnessari,
Nebusaradani, balogun iṣọ, kó ọtadilẹgbẹ-
rin enia o di marun awọn ara Juda ni
igbekun lọ: gbogbo awọn enia na jẹ ẹgbẹ-
talelogun.
31 O si ṣe, li ọdun kẹtadilogoji Jehoi-
akimu, ọba Juda, li oṣu kejila, li ọjọ kẹdọ-
gbọn oṣu, Efil-Merodaki, ọba Babeli, li
ọdun ekini ijọba rẹ̀, o gbe ori Jehoiakimu,
ọba Juda soke, o si mu u jade ninu ile
túbu.
32 O si sọ̀rọ rere fun u, o si gbe itẹ rẹ̀ ga
jù itẹ awọn ọba ti o wà pẹlu rẹ̀ ni Babeli.
33 O si parọ aṣọ túbu rẹ̀: o si njẹun ni-
gbagbogbo niwaju rẹ̀ ni gbogbo ọjọ aiye rẹ̀.
34 Ati ipin onjẹ rẹ̀, ipin onjẹ igbagbo-
gbo, ti ọba Babeli nfi fun u lojojumọ ni
ipin tirẹ̀, titi di ọjọ ikú rẹ̀, ni gbogbo ọjọ
aiye rẹ̀.

# ẸKÚN JEREMIAH.

## ORI 1.

BAWO ni ilu ṣe joko nikan, eyi ti o ti
kún fun enia! o wà bi opó! on ti iṣe
ẹni-nla lãrin awọn orilẹ-ède! ọmọ-alade
obirin lãrin igberiko, on di jijọsin!
2 On sọkun gidigidi li oru, omije rẹ̀ si
wà ni ẹ̀rẹkẹ rẹ̀: lãrin gbogbo awọn olufẹ
rẹ̀, kò ni ẹnikẹni lati tù u ninu: gbogbo
awọn ọrẹ rẹ̀ ti ba a lo ẹ̀tan, nwọn di ọta rẹ̀.
3 Juda lọ si àjo nitori ipọnju ati isin-ẹrú
nla: o joko lãrin awọn orilẹ-ède, on kò ri
isimi: gbogbo awọn ti nlepa rẹ̀ ba a ni ibi
hiha.
4 Ọna Sioni wọnni nṣọ̀fọ, nitori ẹnikan
kò wá si ajọ-mimọ́: gbogbo ẹnu-bode rẹ̀
dahoro: awọn alufa rẹ̀ kẹdun, awọn wundia
rẹ̀ nkãnu, on si wà ni kikoro ọkàn.
5 Awọn aninilara rẹ̀ bori, awọn ọta rẹ̀ ri
rere: nitori Oluwa ti pọn ọ loju nitori ọ̀pọ-
lọpọ irekoja rẹ̀; awọn ọmọ wẹrẹ rẹ̀ lọ si
igbekun niwaju awọn aninilara.
6 Gbogbo ẹwà ọmọbirin Sioni si ti lọ
kuro lọdọ rẹ̀: awọn ijoye rẹ̀ dabi agbọnrin
ti kò ri pápá oko tutu, nwọn si lọ laini
agbara niwaju alepa nì.
7 Li ọjọ ipọnju rẹ̀ ati inilara rẹ̀ ni Jeru-
salemu ranti gbogbo ohun daradara ti o ti
ni li ọjọ igbãni, nigbati awọn enia rẹ̀ ṣubu
si ọwọ ọta, ẹnikan kò si ràn a lọwọ: awọn
aninilara ri i, nwọn si fi iparun rẹ̀ ṣẹsin.
8 Jerusalemu ti da ẹ̀ṣẹ gidigidi, nitorina
li o ṣe di ẹni-irira: gbogbo awọn ti mbu
ọla fun u kẹgan rẹ̀, nitoripe nwọn ri ihoho
rẹ̀: lõtọ on kẹdùn, o si yi ẹ̀hin pada.
9 Ẽri rẹ̀ wà ni iṣẹti aṣọ rẹ̀; on kò si ranti
opin rẹ̀ ikẹhin; nitorina ni o ṣe sọkalẹ ni
isọkalẹ iyanu: kò ni olutunu, Oluwa, wò
ipọnju mi, nitori ọta ti bori!
10 Aninilara ti nà ọwọ rẹ̀ jade sori gbo-
gbo ohun daradara rẹ̀: nitori on ti ri pe
awọn orilẹ-ède wọ ibi-mimọ́ rẹ̀, eyiti iwọ
paṣẹ pe, nwọn kì o wọ inu ijọ tirẹ.
11 Gbogbo awọn enia rẹ̀ kẹdùn, nwọn
wá onjẹ; nwọn fi ohun daradara fun onjẹ
lati tu ara wọn ninu. Wò o Oluwa, ki o si
rò! nitori emi di ẹni-ẹ̀gan.
12 Kò ha kàn nyin bi, gbogbo ẹnyin ti
nkọja? Wò o, ki ẹ si ri bi ibanujẹ kan ba
wà bi ibanujẹ mi, ti a ṣe si mi! eyiti Olu-
wa fi pọn mi loju li ọjọ ibinu gbigbona rẹ̀.
13 Lati oke li a ti rán iná sinu egungun
mi, o si ràn ninu rẹ̀: On ti nà àwọn fun
ẹsẹ mi, o ti yi mi pada sẹhin: O ti mu mi
dahoro, mo si rẹ̀wẹsi lojojumọ.
14 Okùn àjaga irekọja mi li a dimu li
ọwọ rẹ̀; a so wọn pọ̀: nwọn yi ọrùn mi ka,
nwọn tẹ agbara mi mọlẹ; Oluwa ti fi mi le
ọwọ awọn ẹniti emi kò le dide si.
15 Oluwa ti tẹ̀ gbogbo awọn akọni mi
mọlẹ labẹ ẹsẹ li arin mi: On ti pe apejọ
sori mi lati tẹ̀ awọn ọdọmọkọnrin mi rẹ́:
Oluwa ti tẹ ifunti fun wundia, ọmọbirin
Juda.
16 Emi nsọkun nitori nkan wọnyi; oju
mi! oju mi ṣàn omi silẹ, nitoripe olutunu

Digitized by Google

ati ẹniti iba mu ọkàn mi sọji jina si mi:
awọn ọmọ mi run, nitoripe ọta bori.
17 Sioni nà ọwọ rẹ̀ jade, kò si sí ẹnikan
lati tù u ninu: Oluwa ti paṣẹ niti Jakobu
pe, ki awọn aninilara rẹ̀ ki o yi i kakiri:
Jerusalemu dabi obirin ẹlẹgbin lãrin wọn.
18 Oluwa ṣe olododo; nitoriti emi ti
ṣọ̀tẹ si aṣẹ ẹnu rẹ̀: gbọ́, (emi bẹ nyin,)
gbogbo ọrilẹ-ède, ẹ si wò ikãnu mi; awọn
wundia mi ati awọn ọdọmọkọnrin mi lọ si
igbekun.
19 Emi pè awọn olufẹ mi, awọn wọnyi
tàn mi jẹ: awọn alufa mi, ati àgbagba mi
jọwọ ẹmi wọn lọwọ ni ilu, nigbati nwọn
nwá onjẹ wọn lati mu ẹmi wọn sọji.
20 Wò o, Oluwa: nitoriti emi wà ninu
ipọnju: inu mi nhó; ọkàn mi yipada ni-
nu mi; nitoriti emi ti ṣọ̀tẹ gidigidi: lode,
idà sọni di alailọmọ, ni ile, o dabi ikú!
21 Nwọn gbọ́ bi emi ti nkẹdùn to: sibẹ
kò si olutunu fun mi: gbogbo awọn ọta mi
gbọ́ iyọnu mi; inu wọn dùn nitori iwọ ti
ṣe e: iwọ o mu ọjọ na wá ti iwọ ti dá,
nwọn o si ri gẹgẹ bi emi.
22 Jẹ ki gbogbo ìwa-buburu wọn wá si
iwaju rẹ; si ṣe si wọn, gẹgẹ bi iwọ ti ṣe si
mi nitori gbogbo irekọja mi: nitori ikẹdùn
mi pọ̀, ọkàn mi si rẹ̀wẹsi.

ORI 2.

BAWO li Oluwa ti fi awọsanma bo ọmọ-
birin Sioni ni ibinu rẹ̀! ti o sọ ẹwa
Israeli kalẹ lati oke ọrun wá si ilẹ, ti kò si
ranti apoti-itisẹ rẹ̀ li ọjọ ibinu rẹ̀!
2 Oluwa ti gbe gbogbo ibugbe Jakobu
mì, kò si da a si: o ti wó ilu-odi ọmọbirin
Juda lulẹ, ninu irunu rẹ̀ o ti lù wọn bolẹ:
o ti sọ ijọba na ati awọn ijoye rẹ̀ di alaimọ́.
3 O ti ke gbogbo iwo Israeli kuro ninu
ibinu gbigbona rẹ̀: o ti fà ọwọ ọtun rẹ̀ sẹ-
hin niwaju ọta, o si jo gẹgẹ bi ọwọ iná ninu
Jakobu ti o jẹrun yikakiri.
4 O ti fà ọrun rẹ̀ gẹgẹ bi ọta: o duro, o
mura ọwọ ọtun rẹ̀ gẹgẹ bi aninilara, o si pa
gbogbo ohun didara ti oju fẹ iri ni agọ
ọmọbirin Sioni, o dà irunu rẹ̀ jade bi iná.
5 Oluwa jẹ gẹgẹ bi ọta: o ti gbe Israeli
mì, o ti gbe gbogbo ãfin rẹ̀ mì: o ti pa ilu
olodi rẹ̀ run, o si ti fi ibanujẹ lori ibanujẹ
fun ọmọbirin Juda.
6 O si ti wó ọgba rẹ̀ lulẹ, gẹgẹ bi àgbala:
o ti pa ibi apejọ rẹ̀ run: Oluwa ti mu ki a
gbagbe ajọ-mimọ́ ati ọjọ isimi ni Sioni, o
ti fi ẹ̀gan kọ̀ ọba ati alufa silẹ ninu ikannu
ibinu rẹ̀.
7 Oluwa ti ṣá pẹpẹ rẹ̀ tì, o ti korira ibi-
mimọ́ rẹ̀, o ti fi ogiri ãfin rẹ̀ le ọwọ ọta;
nwọn ti pa ariwo ninu ile Oluwa, gẹgẹ bi
li ọjọ ajọ-mimọ́.
8 Oluwa ti rò lati pa odi ọmọbirin Sioni
run: o ti nà okùn ìwọn jade, on kò ti ifa
ọwọ rẹ̀ sẹhin kuro ninu ipanirun: bẹ̃ni o
ṣe ki ile-iṣọ rẹ̀ ati odi rẹ̀ ki o ṣọ̀fọ; nwọn
jumọ rẹ̀ silẹ.
9 Ẹnu-bode rẹ̀ wọnni rì si ilẹ; o ti pa-
run o si ṣẹ́ ikere rẹ̀; ọba rẹ̀ ati awọn ijoye
rẹ̀ wà lãrin awọn orilẹ-ède: ofin kò si mọ;
awọn woli rẹ̀ pẹlu kò ri iran lati ọdọ
Oluwa.
10 Awọn àgbagba ọmọbirin Sioni joko
ni ilẹ, nwọn dakẹ: nwọn ti ku ekuru sori
wọn; nwọn ti fi aṣọ-ọ̀fọ di ara wọn: awọn
wundia Jerusalemu so ori wọn kọ́ si ilẹ.
11 Oju mi gbẹ tan fun omije, inu mi
nho, a dà ẹ̀dọ mi sori ilẹ, nitori iparun
ọmọbirin awọn enia mi; nitoripe awọn
ọmọ wẹrẹ ati awọn ọmọ-ọmu nkulọ ni ita
ilu na.
12 Nwọn nsọ fun iya wọn pe, Nibo ni
ọka ati ọti-waini gbe wà? nigbati nwọn
daku gẹgẹ bi awọn ti a ṣalọgbẹ ni ita ilu
na, nigbati ọkàn wọn dà jade li aiya iya
wọn.
13 Kili ohun ti emi o mu fi jẹri niwaju
rẹ? kili ohun ti emi o fi ọ we, iwọ ọmọ-
birin Jerusalemu? kili emi o fi ba ọ dọgba,
ki emi ba le tù ọ ninu, iwọ wundia ọmọ-
birin Sioni? nitoripe ọgbẹ rẹ tobi gẹgẹ bi
okun; tali o le wò ọ sàn.
14 Awọn woli rẹ ti riran ohun asan ati
wère fun ọ: nwọn kò si ti fi aiṣedede rẹ
hàn ọ, lati yi igbekun rẹ pada kuro; ṣu-
gbọn nwọn ti riran ọ̀rọ-wiwo eke fun ọ ati
imuniṣina.
15 Gbogbo awọn ti nkọja patẹwọ le o;
nwọn nṣesin, nwọn si nmì ori wọn si ọmọ-
birin Jerusalemu; pe, Ilu na ha li eyi, ti a
npè ni: Pipe-ẹwà, Ayọ̀ gbogbo ilẹ aiye!
16 Gbogbo awọn ọta rẹ ya ẹnu wọn si ọ;
nwọn nṣe ṣiọ! nwọn si npa ehin keke,
nwọn wipe: Awa ti gbe e mì; dajudaju
eyi li ọjọ na ti awa ti nwọ̀na fun; ọwọ ti
tẹ ẹ, awa ti ri i!
17 Oluwa ti ṣe eyi ti o ti rò; o ti mu
ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ ti o ti paṣẹ li ọjọ igbãni: o ti bì
ṣubu, kò si dasi: o si ti mu ọta yọ̀ lori rẹ,
o ti gbe iwo awọn aninilara rẹ soke.
18 Ọkàn wọn kigbe si Oluwa, iwọ odi
ọmọbirin Sioni, jẹ ki omije ṣan silẹ gẹgẹ bi
odò lọsan ati loru; má fun ara rẹ ni isimi;
máṣe jẹ ki ẹyin oju rẹ gbe jẹ.
19 Dide, kigbe soke li oru ni ibẹrẹ ako-

Digitized by Google

ko iṣọ: tú ọkàn rẹ jade gẹgẹ bi omi niwaju Oluwa: gbe ọwọ rẹ soke si i fun ẹmi awọn ọmọ wẹwẹ rẹ, ti nkulọ fun ebi ni gbogbo ori-ita.
20 Wò o, Oluwa, ki o rò, fun tani iwọ ti ṣe eyi? Awọn obirin ha le ma jẹ eso-inu wọn, awọn ọmọ-ọwọ ti nwọn npọn? a ha le ma pa alufa ati woli ni ibi mimọ Oluwa?
21 Ewe ati arugbo dubulẹ ni ita wọnni: awọn wundia mi ati awọn ọdọmọkọnrin mi ṣubu nipa idà: iwọ ti pa li ọjọ ibinu rẹ; iwọ ti pa, iwọ kò si dasi.
22 Iwọ ti kepe ẹru mi yikakiri gẹgẹ bi li ọjọ mimọ, tobẹ̃ ti ẹnikan kò sala tabi kì o kù li ọjọ ibinu Oluwa: awọn ti mo ti pọn ti mo si tọ, ni ọta mi ti run.

## ORI 3.

EMI ni ọkọnrin na ti o ti ri wàhala nipa ọpa ibinu rẹ̀.
2 O ti fà mi, o si mu mi wá sinu òkunkun, kì si iṣe sinu imọlẹ.
3 Lõtọ, o yi ọwọ rẹ̀ pada si mi siwaju ati siwaju li ọjọ gbogbo.
4 O ti sọ ẹran-ara mi ati àwọ mi di ogbó, o ti fọ egungun mi.
5 O ti mọdi tì mi, o fi orõrò ati ãrẹ̀ yi mi ka.
6 O ti fi mi si ibi òkunkun, bi awọn ti o ti kú pẹ.
7 O ti sọgba yi mi ka, ti emi kò le jade; o ti ṣe ẹ̀wọn mi wuwo.
8 Bi emi ti kigbe pẹlu, ti emi si npariwo, o sé adura mi mọ.
9 O ti fi okuta gbigbẹ sọgba yi ọ̀na mi ka, o ti yi ipa ọ̀na mi po.
10 On jẹ bi ẹranko beari ti o ba dè mi, bi kiniun ni ibi ìkọkọ.
11 O ti mu mi ṣina li ọ̀na mi, o si fà mi ya pẹrẹpẹrẹ: o ti sọ mi di ahoro.
12 O ti fà ọrun rẹ̀, o si fi mi ṣe itasi fun ọfa rẹ̀.
13 O ti mu ki ọfà apó rẹ̀ wọ inu-ẹdọ mi lọ.
14 Emi jẹ ẹni ẹsin fun gbogbo enia mi; orin wọn ni gbogbo ọjọ.
15 O ti fi ìkoro mu mi yo, o ti mu mi mu omi wahala.
16 O ti fi ọta ṣẹ́ ehín mi, o tẹ̀ mi mọlẹ ninu ẽru.
17 Iwọ si ti mu ọkàn mi jina rére si alafia: emi gbagbe rere.
18 Emi si wipe, Agbara mi ati ireti mi ṣègbe kuro lọdọ Oluwa.
19 Ranti wahala mi ati inilara mi, ani ìkoro ati orõro.
20 Lõtọ, nigbati ọkàn mi nṣe iranti wọn, o si tẹriba ninu mi.
21 Eyi ni emi o rò li ọkàn mi, nitorina emi o ma reti.
22 Ãnu Oluwa ni, ti awa kò parun tan, nitori irọnu-ãnu rẹ kò li opin.
23 Ọtun ni li orowurọ: titobi ni otitọ rẹ.
24 Oluwa ni ipin mi, bẹ̃li ọkàn mi wi; nitorina ni emi ṣe reti ninu rẹ̀.
25 Oluwa ṣe rere fun gbogbo ẹniti o duro dè e, fun ọkàn ti o ṣafẹri rẹ̀.
26 O dara ti a ba mã reti ni idakẹjẹ fun ìgbala Oluwa.
27 O dara fun ọkọnrin, ki o gbe àjaga ni igba-ewe rẹ̀.
28 Ki o joko on nikan, ki o si dakẹ, nitori Ọlọrun ti gbe e le ori rẹ̀.
29 Ki o fi ẹnu rẹ̀ sinu ekuru; pe bọya ireti le wà:
30 Ki o fi ẹ̀rẹkẹ fun ẹniti o lù u; ki o kún fun ẹ̀gan patapata.
31 Nitoriti Oluwa kì yio ṣá ni tì lailai:
32 Bi o tilẹ mu ibanujẹ wá, sibẹ on o ni irọnu gẹgẹ bi ọ̀polopo ãnu rẹ̀.
33 Nitori on kì ifẹ ipọn-ni-loju lati ọkàn rẹ̀ wá, bẹ̃ni kì ibà ọmọ enia ninu jẹ.
34 Lati tẹ̀ gbogbo ara-tubu ilẹ-aiye mọlẹ li abẹ ẹsẹ rẹ̀.
35 Lati yi ẹ̀tọ enia sapakan niwaju Ọgaogo julọ.
36 Lati yi ọ̀ran idajọ enia pada, Oluwa kò fẹ ri i?
37 Tali ẹniti iwi, ti isi iṣẹ, nigbati Oluwa kò paṣẹ rẹ̀.
38 Ibi ati rere kò ha njade lati ẹnu Ọgaogo-julọ wá?
39 Ẽṣe ti enia alãye nkùn? ti o wà lãye, ki olukuluku ki o kùn nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀!
40 Jẹ ki a wádi, ki a si dán ọ̀na wa wò, ki a si tun yipada si Oluwa.
41 Jẹ ki a gbe ọkàn ati ọwọ wa soke si Ọlọrun li ọrun.
42 Awa ti dẹṣẹ, a si ti ṣọtẹ: iwọ kò ti dariji.
43 Iwọ ti fi ibinu bora, o si ṣe inu-nibini si wa: iwọ ti pa, o kò si ti dasi.
44 Iwọ ti fi awọsanma bo ara rẹ, ki adura má le là kọja.
45 Iwọ ti ṣe wa bi idarọ ati ohun alainilãri li ãrin awọn orilẹ-ède.
46 Gbogbo awọn ọta wa ti ya ẹnu wọn si wa.
47 Ẹ̀ru ati ọ̀fin wá sori wa, idahoro ati iparun.

Digitized by Google

48 Oju mi fi odò omi ṣan silẹ, nitori
iparun ọmọbirin awọn enia mi.
49 Oju mi dà silẹ ni omije, kò si dá,
laiṣe isimi.
50 Titi Oluwa fi wò ilẹ, ti o wò lati ọrun
wà,
51 Oju mi npọn ọkàn mi loju, nitori
gbogbo awọn ọmọbirin ilu mi.
52 Awọn ọta mi dẹkùn fun mi gidigidi,
gẹgẹ bi fun ẹiyẹ laini idi.
53 Nwọn ti ke ẹmi mi kuro ninu iho,
nwọn si yi okuta sori mi.
54 Nwọn mu omi ṣan lori mi; emi wipe,
Mo gbe!
55 Emi kepe orukọ rẹ, Oluwa, lati iho
jijin wá.
56 Iwọ ti gbọ́ ohùn mi: máṣe se eti rẹ
mọ si imikanlẹ mi, si igbe mi.
57 Iwọ sunmọ itosi li ọjọ ti emi kigbe
pè ọ: iwọ wipe: Má bẹru!
58 Oluwa, iwọ ti gba ijà mi jà; iwọ ti
rà ẹmi mi pada.
59 Oluwa, iwọ ti ri inilara mi, ṣe idajọ
ọran mi!
60 Iwọ ti ri gbogbo igbẹsan wọn, gbogbo
èro buburu wọn si mi.
61 Iwọ ti gbọ́ ẹ̀gan wọn, Oluwa, gbogbo
èro buburu wọn si mi.
62 Ète awọn wọnnì ti o dide si mi, ati
ipinnu wọn si mi ni gbogbo ọjọ.
63 Kiyesi ijoko wọn ati idide wọn! emi
ni orin-ẹsin wọn.
64 San ẹsan fun wọn, Oluwa, gẹgẹ bi iṣẹ
ọwọ wọn.
65 Fun wọn ni ifọju ọkàn, ẹ̀gun rẹ lori
wọn!
66 Fi ibinu lepa wọn, ki o si pa wọn run
kuro labẹ ọrun Oluwa!

## ORI 4.

BAWO ni wura ṣe di baibai! bawo ni
wura didara julọ ṣe pada! okuta ibi-
mimọ́ li a tuka ni gbogbo ori ita.
2 Awọn ọmọ iyebiye Sioni, ti o niye lori
bi wura didara, bawo li a ṣe kà wọn si bi
ikoko amọ̀, iṣẹ ọwọ alamọ̀!
3 Ani ọ̀wawa nfà ọmu jade, nwọn nfi
ọmu fun awọn ọmọ wọn: ṣugbọn ọmọbirin
awọn enia mi ti di ìka, gẹgẹ bi abo ògongo
li aginju.
4 Ahọn ọmọ-ọmu lẹ̀ mọ oke ẹnu rẹ̀ ni-
tori ongbẹ: awọn ọmọ kekere mbere onjẹ,
ẹnikan kò si bu u fun wọn.
5 Awọn ti o ti njẹ ohun didùndidùn nkú
lọ ni ita: awọn ti a ti tọ́ ninu aṣọ-òdodó,
gbá ãtàn mọra.
6 Nitori aiṣedede ọmọbirin awọn enia
mi tobi jù ẹ̀ṣẹ Sodomu lọ, ti a bì ṣubu ni
iṣẹju, laisi iṣiṣẹ ọwọ ninu rẹ̀.
7 Awọn Nasire rẹ̀ mọ́ jù ẹ̀gbọn-owu,
nwọn funfun jù wàra; irisi wọn pọn jù
iyùn, apẹrẹ wọn dabi okuta Safire:
8 Oju wọn dudu jù ẽdu nisisiyi; a kò
mọ̀ wọn ni ita: àwọ wọn lẹ mọ egungun
wọn; o di gbigbẹ gẹgẹ bi igi.
9 Awọn ti a fi idà pa san jù awọn ti a fi
ebi pa, ti ndaku, ti a gún wọn lara nitori
aisi eso-oko.
10 Ọwọ awọn obirin alãnu ti sè awọn
ọmọ awọn tikarawọn: awọn wọnyi li ohun
jijẹ fun wọn ni igba wahala ọmọbirin awọn
enia mi.
11 Oluwa ti ṣe aṣepe irunu rẹ̀; o ti dà
ibinu gbigbona rẹ̀ jade, o ti dá iná ni Sioni,
ti o si ti jo ipilẹ rẹ̀ run.
12 Awọn ọba aiye, ati gbogbo olugbe ilẹ-
aiye, kò gbagbọ pe aninilara ati ọta iba ti
wọ inu ẹnu-bode Jerusalemu.
13 Nitori ẹ̀ṣẹ awọn woli rẹ̀, ati aiṣedede
awọn alufa rẹ̀, ti nwọn ti ta ẹ̀jẹ awọn olo-
dodo silẹ li ãrin rẹ̀.
14 Nwọn ti rin kiri bi afọju ni ita, nwọn
di alaimọ́ fun ẹ̀jẹ, tobẹ̃ ti enia kò le fi ọwọ
kan aṣọ wọn.
15 Nwọn nkigbe si wọn pe, ẹ lọ! alaimọ́
ni! ẹ lọ! ẹ lọ! ẹ máṣe fi ọwọ kan a! ni-
gbati nwọn salọ, nwọn si rìn kiri pẹlu:
nwọn nwi lãrin awọn orilẹ-ède pe, awọn kì
o ṣatipo nibẹ mọ.
16 Oju Oluwa ti tú wọn ka: on kì o
fiyesi wọn mọ: nwọn kò buyin fun awọn
alufa, nwọn kò ṣãnu fun awọn àgbagba.
17 Bi o ṣe ti wa ni, oju wa nwọ̀na siwaju
ati siwaju, fun iranlọwọ wa ti o jẹ asan:
lori ile-iṣọ wa, awa nwọ̀na fun orilẹ-ède, ti
kò le ràn ni lọwọ.
18 Nwọn dẹkun si ipa ọ̀na wa, ti awa
kò le rìn ita wa: opin wa sunmọ tosi, ọjọ
wa pé; nitori opin wa de.
19 Awọn ti nlepa wa yara jù idì ọrun
lọ: nwọn nlepa wa lori oke wọnni, nwọn
bà dè wa li aginju.
20 Ẹmi iho imu wa, ani ẹni-ororo Oluwa,
ni a mu ninu ọ̀fin wọn, niti ẹniti awa wipe,
labẹ ojiji rẹ̀ li awa o ma gbé lãrin awọn
orilẹ-ède.
21 Yọ̀, ki inu rẹ si dùn, iwọ ọmọbirin
Edomu, ti ngbe inu ilẹ Usi; sibẹ ago na
yio kọja sọdọ rẹ pẹlu: iwọ o si yo bi
ọmuti, a o si tu ọ ni ihoho.
22 A mu aiṣedede rẹ kuro, iwọ ọmọbirin
Sioni: on kì o si tun mu ọ lọ si igbekun

Digitized by Google

mọ : On o bẹ̀ aiṣedede rẹ wò, iwọ ọmọbirin Edomu ; yio si fi ẹ̀ṣẹ rẹ hàn.

ORI 5.

RANTI, Oluwa, ohun ti o de sori wa ; rò ki o si wò ẹ̀gan wa!

2 A fi ogún wa le awọn alejo lọwọ, ile wa fun awọn ajeji.

3 Awa jẹ alaini õbi, baba kò si, awọn iyá wa dabi opó.

4 Awa ti fi owo mu omi wa ; a nta igi wa fun wa.

5 Awọn ti nlepa wa sunmọ ọrùn wa : ãrẹ̀ mu wa, awa kò si ni isimi.

6 Awa ti fi ọwọ wa fun awọn ara Egipti, ati fun ara Assiria, lati fi onjẹ tẹ́ wa lọrùn.

7 Awọn baba wa ti ṣẹ̀, nwọn kò si sí ; awa si nrù aiṣedede wọn.

8 Awọn ẹrú ti jọba lori wa : ẹnikan kò si gbà wa kuro li ọwọ wọn.

9 Ninu ewu ẹmi wa li awa nlọ mu onjẹ wa, nitori idà ti aginju.

10 Àwọ wa pọ́n gẹgẹ bi àro nitori gbigbona ìyan na.

11 Nwọn tẹ́ awọn obirin li ogo ni Sioni, awọn wundia ni ilu Juda.

12 A so awọn ijoye rọ̀ nipa ọwọ wọn : a kò buyin fun oju awọn àgbagba.

13 Awọn ọdọmọkọnrin ru ọlọ, ãrẹ̀ mu awọn ọmọde labẹ ẹrù-igi.

14 Awọn àgbagba dasẹ kuro li ẹnubode, awọn ọdọmọkọnrin kuro ninu orin wọn.

15 Ayọ̀ ọkàn wa ti dá ; a yi ijo wa pada si ọ̀fọ.

16 Ade ṣubu kuro li ori wa : ègbe ni fun wa, nitori awa ti ṣẹ̀.

17 Nitori eyi li ọkàn wa rẹ̀wẹsi ; nitori nkan wọnyi oju wa di baibai.

18 Nitori oke Sioni, ti dahoro, awọn kọ̀lọkọlọ nrin lori rẹ̀.

19 Iwọ, Oluwa, li o wà lailai ; itẹ́ rẹ lati iran de iran!

20 Ẽṣe ti iwọ fi gbagbe wa lailai, ti o si kọ̀ wa silẹ li ọjọ pipẹ?

21 Oluwa, yi wa pada sọdọ rẹ, awa o si yipada ; sọ ọjọ wa di ọtun gẹgẹ bi ti igbãni.

22 Tabi iwọ ha ti kọ̀ wa silẹ patapata, tobẽ ti iwọ si binu si wa gidigidi?

IWE WOLI

# ESEKIELI.

ORI 1.

OSI ṣe li ọgbọ̀n ọdun, ni oṣu ẹkẹrin, li ọjọ ẹ̀karun oṣu, bi mo ti wà lãrin awọn igbekùn leti odo Kebari, ọrun ṣi, mo si ri iran Ọlọrun.

2 Li ọjọ karun oṣu, ti iṣe ọdun karun igbekùn Jehoiakini ọba,

3 Ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Esekieli alufa, ọmọ Busi wá papã, ni ilẹ awọn ara Kaldea leti odò Kebari, ọwọ́ Oluwa si wà li ara rẹ̀ nibẹ.

4 Mo si wò, si kiye si i, ãja jade wá lati ariwa, awọsanma nla, ati iná ti o yi ara rẹ̀ ka, didán si wà yika, ani lati ãrin rẹ̀ wá, bi àwọ amberi, lati ãrin iná na wá.

5 Pẹlupẹlu lati ãrin rẹ̀ wá, aworan ẹda alãye mẹrin, eyi si ni irí wọn, awọn ni aworan enia.

6 Olukuluku si ni oju mẹrin, olukuluku si ni iyẹ mẹrin.

7 Ẹsẹ wọn si tọ́, atẹlẹṣẹ wọn si dabi atẹlẹṣẹ ọmọ malũ : nwọn si tàn bi awọ̀ idẹ didan.

8 Nwọn si ni ọwọ́ enia labẹ iyẹ́ wọn, li ẹgbẹ wọn mẹrẹrin, awọn mẹrẹrin si ni oju wọn ati iyẹ́ wọn.

9 Iyẹ́ wọn si kàn ara wọn ; nwọn kò yipada nigbati nwọn lọ, olukuluku wọn lọ li ọkankan ganran.

10 Niti aworan oju wọn, awọn mẹrẹrin ni'oju enia, ati oju kiniun, niha ọtun : awọn mẹrẹrin si ni oju malu niha osì ; awọn mẹrẹrin si ni oju idì.

11 Bayi li oju wọn ri : iyẹ́ wọn si nà soke, iyẹ́ meji olukuluku wọn kàn ara wọn, meji si bo ara wọn.

Digitized by Google

12 Olukuluku wọn si lọ li ọkankan gan-
ran: nibiti ẹmi ibá lọ, nwọn lọ; nwọn kò
si yipada nigbati nwọn lọ.
13 Niti aworan awọn ẹda alãye na, irí
wọn dabi ẹṣẹ́ iná, ati bi irí inà fitila: o lọ
soke ati sodo, lãrin awọn ẹda alãye na, iná
na si mọlẹ, manamana si jade lati inu iná
na wá.
14 Awọn ẹda alãye na si sure, awọn si
pada bi kíkọ manamana.
15 Bi mo si ti wo awọn ẹda alãye na,
kiyesi i, kẹkẹ́ kan wà lori ilẹ aiye lẹba
awọn ẹda alãye na, pẹlu oju rẹ̀ mẹrin.
16 Irí awọn kẹkẹ́ na ati iṣẹ wọn dabi
awọ̀ berili: awọn mẹrẹrin ni aworan kanna;
irí wọn ati iṣẹ wọn dabi ẹnipe kẹkẹ́ li ãrin
kẹkẹ́.
17 Nigbati nwọn lọ, nwọn fi iha wọn
mẹrẹrin lọ, nwọn kò si yipada nigbati
nwọn lọ.
18 Niti oruka wọn, nwọn ga tobẽ ti
nwọn fi ba ni li ẹ̀ru; oruka wọn si kún fun
oju yi awọn mẹrẹrin ka.
19 Nigbati awọn ẹda alãye na lọ, awọn
kẹkẹ́ lọ li ẹgbẹ́ wọn: nigbati a si gbe awọn
ẹda alãye na soke, kuro lori ilẹ, a gbe awọn
kẹkẹ́ na soke pẹlu.
20 Nibikibi ti ẹmi ni iba lọ, nwọn lọ;
nibẹ li ẹmi fẹ ilọ: a si gbe awọn kẹkẹ́ na
soke pẹlu wọn; nitori ẹmi iye wà ninu
awọn kẹkẹ́ na.
21 Nigbati wọnni lọ, wọnyi lọ; nigbati
a gbe wọnni duro, wọnyi duro; ati nigbati
a gbe wọnni soke kuro lori ilẹ a gbe kẹkẹ́
soke pẹlu wọn: nitori ẹmi iye wà ninu
awọn kẹkẹ́ na.
22 Aworan ofurufu li ori ẹda alãye na
dabi àwọ kristali ti o ba ni li ẹ̀ru, ti o nà
sori wọn loke.
23 Iyẹ́ wọn si tọ́ labẹ ofurufu, ekini si
ekeji: olukuluku ni meji, ti o bo ihà ihín,
olukuluku si ni meji ti o bo iha ọhún ara
wọn.
24 Nigbati nwọn si lọ, mo gbọ́ ariwo iyẹ́
wọn, bi ariwo omi pupọ, bi ohùn Olodu-
mare, ohùn ọ̀rọ bi ariwo ogun: nigbati
nwọn duro, nwọn rẹ̀ iyẹ́ wọn silẹ.
25 Ohùn kan ti inu ofurufu ti o wà lori
wọn wá, nigbati nwọn duro, ti nwọn si ti
rẹ̀ iyẹ́ wọn silẹ.
26 Ati lori ofurufu ti o wà lori wọn,
aworan itẹ kan wà, bi irí okuta safire: ati
loke aworan itẹ na li aworan kan bi ori
enia wà.
27 Mo si ri bi awọ amberi, bi irí iná yika
ninu rẹ̀, lati irí ẹgbẹ́ rẹ̀ de oke, ati lati irí
ẹgbẹ́ rẹ̀ de isalẹ, mo ri bi ẹnipe irí iná, o si
ni didan yika.
28 Bi irí oṣumare ti o wà ninu awọ-
sanma ni ọjọ ojo, bẽni irí didan na yika.
Eyi ni aworan ogo Oluwa. Nigbati mo si
ri, mo dojubolẹ, mo si gbọ́ ohùn ẹnikan ti
nsọ̀rọ.

## ORI 2.

O SI wi fun mi pe, Ọmọ enia, duro li ẹsẹ
rẹ, emi o si ba ọ sọ̀rọ.
2 Ẹmi si wọ inu mi, nigbati o ba mi sọ̀rọ
o si gbe mi duro li ẹsẹ mi, mo si gbọ́ ẹniti
o ba mi sọrọ.
3 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, emi ran
ọ si awọn ọmọ Israeli, si ọlọtẹ̀ orilẹ-ède, ti
o ti ṣọtẹ si mi: awọn ati baba wọn ti ṣẹ̀ si
mi titi di oni oloni.
4 Nitori ọmọ alafojudi ati ọlọkàn lile ni
nwọn, Emi rán ọ si wọn; iwọ o si wi fun
wọn pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi.
5 Ati awọn, bi nwọn o gbọ́, tabi bi nwọn
o kọ̀, (nitori ọlọtẹ̀ ile ni nwọn) sibẹ nwọn
o mọ̀ pe woli kan ti wà larin wọn.
6 Ati iwọ, ọmọ enia, máṣe bẹ̀ru wọn,
bẽni ki o máṣe bẹ̀ru ọ̀rọ wọn, bi ẹgun ọgàn
ati oṣuṣu tilẹ pẹlu rẹ, ti iwọ si gbe ãrin
akẽkẽ: máṣe bẹ̀ru ọ̀rọ wọn, bẽni ki o máṣe
foya wiwò wọn, bi nwọn tilẹ jẹ ọlọtẹ̀ ile.
7 Iwọ o si sọ ọ̀rọ mi fun wọn, bi nwọn o
gbọ́, tabi bi wọn o kọ̀: nitoriti nwọn jẹ
ọlọtẹ̀.
8 Ṣugbọn iwọ, ọmọ enia, gbọ́ ohun ti mo
sọ fun ọ; Iwọ máṣe jẹ ọlọtẹ̀ bi ọlọtẹ̀ ile nì:
ya ẹ̀nu rẹ, ki o si jẹ ohun ti mo fi fun ọ.
9 Nigbati mo wò, si kiye si i, a ran ọwọ́
kan si mi; si kiye si i, iká-iwé kan wà
ninu rẹ̀.
10 O si tẹ́ ẹ siwaju mi, a si kọ ọ ninu
ati lode: a si kọ ohùn-reré-ẹkun, ati ọ̀fọ,
ati egbe.

## ORI 3.

PẸLUPẸLU o wi fun mi pe, Ọmọ enia, jẹ
ohun ti iwọ ri, jẹ iká-iwé yi, si lọ ba
ile Israeli sọrọ.
2 Mo si ya ẹnu mi, o si mu mi jẹ iká-iwé
na.
3 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, mu ki
ikùn rẹ jẹ, ki o si fi iká-iwé yi ti emi fi fun
ọ kún inu rẹ. Nigbana ni mo jẹ ẹ, o si
dabi oyin li ẹnu ni didùn.
4 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, Lọ, tọ̀
ile Israeli lọ ki o si fi ọ̀rọ mi ba wọn sọrọ.
5 Nitori a kò ran ọ si enia ède ajeji ati
ṣíṣoro, ṣugbọn si ile Israeli.

Digitized by Google

6 Ki iṣe si ọ̀pọlọpọ enia ède ajeji, ati
ède ṣiṣoro, ọ̀rọ ẹniti iwọ kò le gbọ́. Nitotọ
emi iba rán ọ si wọn, nwọn iba gbọ́ tirẹ.
7 Ṣugbọn ile Israeli kò ni gbọ́ tirẹ;
nitori ti nwọn kò fẹ gbọ́ ti emi: nitori
alafojudi ati ọlọkàn lile ni gbogbo ile
Israeli.
8 Kiyesi i, mo ti sọ oju rẹ di lile si oju
wọn, ati iwaju rẹ di lile si iwaju wọn.
9 Bi okuta diamondi ti o le ju okuta
ibọn ni mo ṣe iwaju rẹ: máṣe bẹ̀ru wọn,
bẽni ki o máṣe fòya oju wọn, bi nwọn tilẹ
jẹ ọlọ̀tẹ ile.
10 Pẹlupẹlu o wi fun mi pe, Ọmọ enia,
gba gbogbo ọ̀rọ ti emi o sọ fun ọ si ọkàn rẹ,
si fi eti rẹ gbọ́ wọn.
11 Si lọ, tọ̀ awọn ti igbekùn lọ, awọn
ọmọ enia rẹ, si ba wọn sọ̀rọ, ki o si wi fun
wọn pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; bi nwọn
o gbọ́, tabi bi nwọn o kọ̀.
12 Ẹmi si gbe mi soke, mo si gbọ́ ohùn
iró nla lẹhin mi, nwipe, Ibukun ni fun ogo
Oluwa lati ipò rẹ̀ wá.
13 Mo si gbọ́ ariwo iyẹ́ awọn ẹ̀da alãye,
ti o kàn ara wọn, ati ariwo awọn kẹkẹ́ ti o
wà pẹlu wọn, ati ariwo iró nla.
14 Bẽni ẹmi na gbe mi soke, o si mu mi
kuro, mo si lọ ni ibinujẹ, ati ninu gbigbona
ọkàn mi; ṣugbọn ọwọ́ Oluwa le lara mi.
15 Nigbana ni mo tọ̀ awọn ti igbekùn ti
Telabibi lọ, ti nwọn ngbe ẹba odo Kebari,
mo si joko nibiti nwọn joko, ẹnu si yà mi
bi mo ti wà lãrin wọn ni ijọ meje.
16 O si di igbati o ṣe li opin ijọ meje,
ọ̀rọ Oluwa wá sọdọ mi, wipe.
17 Ọmọ enia, mo ti fi iwọ ṣe oluṣọ́ fun
ile Israeli, nitorina gbọ́ ọ̀rọ li ẹnu mi, si
kilọ fun wọn lati ọdọ mi wá.
18 Nigbati emi wi fun enia buburu pe,
Iwọ o kú nitõtọ; ti iwọ kò si kilọ̀ fun u, ti
iwọ kò sọ̀rọ lati kilọ fun enia buburu, lati
kuro li ọ̀na buburu rẹ̀, lati gba ẹmi rẹ̀ là;
enia buburu na yio kú ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀; ṣugbọn
ẹjẹ rẹ̀ li emi o bere li ọwọ́ rẹ.
19 Ṣugbọn bi iwọ ba kilọ̀ fun enia bu-
buru, ti kò si kuro ninu buburu rẹ̀, ti ko
yipada kuro li ọ̀na buburu rẹ̀, yio kú ninu
ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ṣugbọn ọrun rẹ mọ́.
20 Ẹwẹ, nigbati olododo ba yipada kuro
ninu ododo rẹ̀, ti o si da ẹ̀ṣẹ, ti mo si fi
ohun idugbolu siwaju rẹ, yio kú; nitoriti
iwọ kò kilọ fun u, yio kú ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, a ki
yio ranti ododo rẹ̀ ti o ti ṣe; ṣugbọn ẹjẹ rẹ̀
li emi o bere li ọwọ́ rẹ.
21 Ṣugbọn bi iwọ ba kilọ fun olododo,
ki olododo ki o má dẹ̀ṣẹ, ti on kò si ṣẹ̀, yio
yè nitotọ, nitori ti a kilọ fun u, ọrùn rẹ si
mọ́.
22 Ọwọ́ Oluwa si wà lara mi nibẹ; o si
wi fun mi pe, Dide, lọ si pẹtẹlẹ, emi o si
ba ọ sọ̀rọ nibẹ.
23 Mo si dide, mo si lọ si pẹtẹlẹ, si ki-
yesi i ogo Oluwa duro nibẹ, bi ogo ti mo ri
lẹba odò Kebari: mo si doju mi bolẹ.
24 Ẹmi si wọ̀ inu mi lọ, o si gbe mi duro
li ẹsẹ mi, o si ba mi sọ̀rọ, o si sọ fun mi pe,
Lọ, há ara rẹ mọ ile rẹ.
25 Ṣugbọn iwọ, ọmọ enia, kiyesi i, nwọn
o si fi idè le ọ, nwọn o si fi dè ọ, iwọ ki yio
si jade larin wọn.
26 Emi o si mu ahọn rẹ lẹ mọ òke ẹnu
rẹ, iwọ o si yadi, iwọ ki yio jẹ abaniwi si
wọn; nitori ọlọ̀tẹ ile ni nwọn.
27 Ṣugbọn nigbati mo ba ọ sọ̀rọ, emi o
ya ẹnu rẹ, iwọ o si wi fun wọn pe, Bayi li
Oluwa Ọlọrun wi; Ẹniti o gbọ́, jẹ ki o
gbọ́; ẹniti o kọ̀, jẹ ki o kọ̀, nitori ọlọ̀tẹ ile
ni nwọn.

## ORI 4.

IWỌ, ọmọ enia, mu awo kan, ki o si fi si
iwaju rẹ, ki o si ṣe aworan ilu Jerusa-
lemu sinu rẹ̀.
2 Ki o si dótì i, ki o si mọ ile iṣọ tì i, ki
o si mọ odi tì i, ki o si gbe ogun si i, ki o
si to õlù yi i ka.
3 Mu awo irin kan, ki o si gbe e duro bi
odi irin lãrin rẹ ati ilu na: ki o si kọju si
i, a o si dótì i, iwọ o si dótì i. Eyi o jẹ
àmi si ile Israeli.
4 Fi iha osì rẹ dubulẹ, ki o si fi ẹ̀ṣẹ ile
Israeli sori rẹ̀: gẹgẹ bi iye ọjọ ti iwọ o
dubulẹ sori rẹ̀ ni iwọ o ru ẹ̀ṣẹ wọn.
5 Nitori mo ti fi ọdun ẹ̀ṣẹ wọn le ọ lori,
gẹgẹ bi iye ọjọ na, ẹwa-di-ni-irinwo ọjọ:
bẽni iwọ o ru ẹ̀ṣẹ Israeli.
6 Nigbati iwọ ba si pari wọn, tun fi
ẹgbẹ́ rẹ ọtún dubulẹ, iwọ o si ru ẹ̀ṣẹ ile
Juda li ogoji ọjọ: mo ti yàn ọjọ kan fun
ọdun kan fun ọ.
7 Nitorina iwọ o kọju si didótì Jerusa-
lemu, iwọ ki yio si bo apá rẹ, iwọ o si sọ
asọtẹlẹ si i.
8 Si kiyesi i, emi o fi idè le ara rẹ, iwọ
ki yio si yipada lati ihà kan de ekeji, titi
iwọ o fi pari gbogbo ọjọ didotì rẹ.
9 Si mu alikama, ati ọka bàba, erẽ ati
lentile ati milleti, ati ẹwẹ, fi wọn sinu iko-
ko kan, ki o si fi wọn ṣe akara, gẹgẹ bi iye
ọjọ ti iwọ o dubulẹ li ẹgbẹ́ rẹ, ẹwa-di-ni-
irinwo ọjọ ni iwọ o jẹ ninu rẹ̀.
10 Iwọ o si jẹ onjẹ rẹ nipa ìwọn, ogún

Digitized by Google

ìwọn ṣekeli li ọjọ kan, lati akoko de akoko
ni iwọ o jẹ ẹ.
11 Iwọ o si mu omi nipa ìwọn, idamẹfa
oṣuwọ̀n hini kan: lati akoko de akoko ni
iwọ o mu u.
12 Iwọ o si jẹ ẹ bi akara ọka bàba, iwọ o
si fi igbẹ́ enia din i, li oju wọn.
13 Oluwa si wipe, Bayi li awọn ọmọ
Israeli yio jẹ akara aimọ́ wọn larin awọn
keferi, nibiti emi o le wọn lọ.
14 Nigbana ni mo wipe, A, Oluwa Ọlọ-
run! kiye si i, a kò ti sọ ọkán mi di aimọ́:
nitori lati igba ewe mi wá titi di isisiyi,
emi kò ti ijẹ ninu ohun ti o kú fun ara rẹ̀,
tabi ti a faya pẹrẹpẹrẹ, bẽni ẹran ẽwọ̀ kò
iti iwọ̀ mi li ẹnu ri.
15 Nigbana ni o wi fun mi pe, Wõ, mo
ti fi ẹlẹbọtọ fun ọ dipò igbẹ́ enia, iwọ o si
fi ṣe akara rẹ.
16 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, kiye si
i, emi o ṣẹ ọpá onjẹ ni Jerusalemu: nwọn
o si jẹ akara nipa ìwọn ati pẹlu itọju;
nwọn o si mu omi nipa ìwọn ati pẹlu
iyanu.
17 Ki nwọn ki o le ṣe alaini akara ati
omi, ki olukuluku wọn ki o le yanu si
ọmọnikeji rẹ̀, ki nwọn si run nitori ẹ̀ṣẹ
wọn.

## ORI 5.

IWỌ, ọmọ enia, mu ọbẹ mimú, mu abẹ
onigbajamọ̀, ki o si mu u kọja li ori rẹ,
ati ni irùngbọn rẹ: si mu oṣuwọ̀n lati wọ̀n,
ki o si pin irun na.
2 Iwọ o si fi iná sun idamẹta li ãrin ilu,
nigbati ọjọ didotì ba pé: iwọ o si mu ida-
mẹta, ki o si fi ọbẹ bù u kakiri: idamẹta
ni iwọ o si tuka sinu ẹfũfù, emi o si yọ idà
tẹle wọn.
3 Iwọ o si mu iye diẹ nibẹ, iwọ o si dì
wọn si eti aṣọ rẹ.
4 Si tun mu ninu wọn, ki o si sọ wọn si
ãrin iná, ki o si sun wọn ninu iná; lati
inu rẹ̀ wá ni iná o ti jade wá si gbogbo ile
Israeli.
5 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Eyi ni
Jerusalemu: Emi ti gbe e kalẹ li ãrin
awọn orilẹ-ède, ati awọn ilẹ ti o wà yi i
ka kiri.
6 O si ti pa idajọ mi dà si buburu ju
awọn orilẹ-ède lọ, ati ilana mi ju ilẹ ti o yi
i kakiri: nitori nwọn ti kọ̀ idajọ ati ilana
mi, nwọn kò rìn ninu wọn.
7 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi:
Nitori ti ẹnyin ṣe ju awọn orilẹ-ède ti o yi
nyin ka kiri lọ, ti ẹnyin kò rìn ninu ilana
mi, ti ẹ kò pa idajọ mi mọ, ti ẹ kò si ṣe
gẹgẹ bi idajọ awọn orilẹ-ède ti o yi nyin ka
kiri.
8 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi:
kiye si i, Emi, ani Emi, doju kọ ọ, emi
o si ṣe idajọ li ãrin rẹ li oju awọn orilẹ-
ède.
9 Emi o si ṣe ninu rẹ ohun ti emi kò ṣe
ri, iru eyi ti emi kì yio si ṣe mọ, nitori
gbogbo ohun irira rẹ.
10 Nitorina awọn baba yio jẹ awọn ọmọ
li ãrin rẹ, ati awọn ọmọ yio si jẹ awọn
baba wọn; emi o si ṣe idajọ ninu rẹ, ati
gbogbo iyokù rẹ li emi o tuka si gbogbo
ẹfũfù.
11 Nitorina Oluwa Ọlọrun wipe, Bi mo
ti wà; Nitõtọ, nitori ti iwọ ti sọ ibi mimọ́
mi di aimọ́ nipa ohun ẹgbin rẹ, ati pẹlu
gbogbo ohun irira rẹ, nitori na li emi o ṣe
dín ọ kù, oju mi kì yio dasi, bẽni emi kì
yio ṣãnu fun ọ.
12 Idámẹta rẹ yio kú nipa ajakalẹ arùn,
nwọn o si run li ãrin rẹ nipa iyàn, idámẹta
yio si ṣubu nipa idà yi ọ ka kiri, emi o si
tú idamẹta ká si gbogbo ẹfũfù, emi o si yọ
idà tẹle wọn.
13 Bayi ni ibinu mi o ṣẹ, emi o si mu
ibinu mi duro lori wọn, inu mi yio si tutù;
nwọn o si mọ̀ pe emi Oluwa ti sọ ọ ninu
itara mi, nigbati mo ba pari ibinu mi ninu
wọn.
14 Emi o si fi ọ ṣòfo, emi o si sọ ọ di
ẹ̀gan lãrin awọn orilẹ-ède ti o yi ọ ka kiri,
li oju gbogbo awọn ti nkọja.
15 Bẽni yio si di ẹ̀gan ati ẹsín, ẹkọ́ ati
iyanu si awọn orilẹ-ède ti o wà yi ọ ka
kiri; nigbati emi o ṣe idajọ ninu rẹ ninu
ibinu, ati ninu irunu on ibawi irunu. Emi
Oluwa li o sọ ọ.
16 Nigbati emi o rán ọfà buburu iyàn
si wọn, eyi ti yio jẹ fun iparun wọn, eyi
ti emi o rán lati run nyin: emi o si sọ
ìyàn di pupọ̀ fun nyin, emi o si ṣẹ́ ọpá onjẹ
nyin.
17 Bẽni emi o rán iyàn ati ẹranko bu-
buru si nyin, nwọn o si gbà ọ li ọmọ, ajà-
kalẹ arùn ati ẹ̀jẹ̀ yio si kọja lãrin rẹ, emi o
si mu idà wá sori rẹ. Emi Oluwa li o ti
sọ ọ.

## ORI 6.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wà, wipe,
2 Ọmọ enia, kọju rẹ si awọn oke-nla
Israeli, si sọtẹlẹ si wọn.
3 Si wipe, Ẹnyin oke-nla Israeli, ẹ gbọ́

Digitized by Google

ọ̀rọ Oluwa Ọlọrun; bayi li Oluwa Ọlọrun
wi si awọn oke-nla, si awọn oke kekeke, si
awọn odò siṣàn, ati si awọn afonifoji; ki-
yesi i, Emi, ani Emi, o mu idà wá sori
nyin, emi o si pa ibi giga nyin run.
4 Pẹpẹ nyin yio si di ahoro, ere nyin yio
si fọ; okú nyin li emi o si gbe jù siwaju
oriṣa nyin.
5 Emi o si tẹ́ okú awọn ọmọ Israeli si-
waju oriṣa wọn; emi o si tú egungun nyin
ka yi pẹpẹ nyin ka.
6 Ilu-nla li a o parun ninu gbogbo ibu-
gbe nyin, ibi giga yio si di ahoro: ki a
le run pẹpẹ nyin, ki a si sọ ọ di ahoro,
ki a si le fọ́ oriṣa nyin, ki o si tan, ki a
si le ké ere nyin lu ilẹ, ki iṣẹ́ nyin si le
parẹ.
7 Okú yio si ṣubu li ãrin nyin, ẹnyin o
si mọ̀ pe, Emi li Oluwa.
8 Ṣugbọn emi o fi iyokú silẹ, ki ẹnyin
le ni diẹ ti yio bọ́ lọwọ idà lãrin awọn
orilẹ-ède, nigbati a o tú nyin ka gbogbo
ilẹ.
9 Awọn ti o bọ́ ninu nyin yio si ranti
mi, lãrin awọn orilẹ-ède nibiti nwọn o gbe
dì wọn ni igbekun lọ, nitoriti mo ti fọ́ ọkàn
agbere wọn ti o ti lọ kuro lọdọ mi, ati pẹlu
oju wọn, ti nṣagbere lọ sọdọ oriṣa wọn:
nwọn o si sú ara wọn nitori ìwa ibi ti nwọn
ti hù ninu gbogbo irira wọn.
10 Nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa, emi
kò wi lasan pe, emi o ṣe ibi yi si wọn.
11 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; pàtẹwọ rẹ,
si fi ẹsẹ rẹ kì ilẹ; si wipe, o ṣe! fun gbo-
gbo irira buburu ilẹ Israeli, nitori nwọn o
ṣubu nipa idà, nipa ìyan, ati nipa ajakalẹ
àrun.
12 Ẹniti o jina rere yio kú nipa ajakalẹ
àrun; ati ẹniti o sunmọ tosí yio ṣubu nipa
idà; ati ẹniti o kù ti a si do tì yio kú nipa
ìyàn: bayi li emi o mu irunu mi ṣẹ lori
wọn.
13 Nigbana li ẹnyin o mọ̀ pe emi li
Oluwa, nigbati okú wọn yio wà larin ere
wọn yi pẹpẹ wọn ka, lori oke kekeke gbo-
gbo, lori ṣonṣo ori oke giga gbogbo, ati
labẹ igi tutu gbogbo, ati labẹ gbogbo igi
oaku bibò, ibiti nwọn ti rubọ õrùn didùn
si gbogbo ere wọn.
14 Bẽ li emi o nà ọwọ́ mi jade sori wọn,
emi o si sọ ilẹ na di ahoro, nitotọ, yio di
ahoro jù aginju iha Diblati lọ, ninu gbo-
gbo ibugbe wọn: nwọn o si mọ̀ pe emi li
Oluwa.

## ORI 7.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
2 Iwọ ọmọ enia, bayi li Oluwa Ọlọrun
wi pẹlu si ile Israeli; Opin, opin de sori
igun mẹrẹrin ilẹ.
3 Opin de si ọ wayi, emi o si rán ibinu
mi sori rẹ, emi o si da ọ lẹjọ gẹgẹ bi ọ̀na
rẹ; emi o si san gbogbo irira rẹ pada si ọ
lori.
4 Oju mi kì yio si dasi, bẽli emi kì yio
ṣãnu: ṣugbọn emi o san ọ̀na rẹ pada si ọ
lori, ati irira rẹ yio wà li ãrin rẹ: ẹnyin o
si mọ̀ pe, emi li Oluwa.
5 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; ibi kan, ibi
kanṣoṣo, kiye si i, o de.
6 Opin de, opin de: o jí si ọ; kiye si i,
o de.
7 Ilẹ mọ́ ọ, iwọ ẹniti ngbe ilẹ na: akokò
na de, ọjọ wahala sunmọ tosí; kì isi ṣe
ariwo awọn oke-nla.
8 Nisisiyi li emi o dà ikọnnu mi si ọ
lori, emi o si mu ibinu mi ṣẹ si ọ lori: emi
o si dá ọ lẹjọ gẹgẹ bi ọ̀na rẹ, emi o si san
fun ọ nitori gbogbo irira rẹ.
9 Oju mi kì yio si dasi, bẽli emi kì yio
ṣãnu: emi o si san fun ọ gẹgẹ bi ọ̀na rẹ,
ati irira rẹ ti mbẹ lãrin rẹ; ẹnyin o si mọ̀
pe emi li Oluwa ti nkọlu.
10 Kiye si i ọjọ na, kiyesi i, o de: ilẹ ti
mọ́; ọpá ti tanná, irera ti rudi.
11 Iwa-ipa ti dide di ọpa ìwa buburu:
ọkan ninu wọn kì yio kù, tabi ninu ọ̀pọ-
lọpọ wọn, tabi ninu ohun kan wọn, bẽni
kì yio si ipohùnrere ẹkun fun wọn.
12 Akoko na de, ọjọ na sunmọ itosi: ki
olùra máṣe yọ̀, bẽni ki olùta máṣe gbãwẹ:
nitori ibinu de ba gbogbo wọn.
13 Nitori olùta kì yio pada si eyi ti a
tà, bi nwọn tilẹ wà lãye: nitori iran na
kàn gbogbo enia ibẹ̀, ti kì yio pada; bẽni
kò si ẹniti yio mu ara rẹ̀ le ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀.
14 Nwọn ti fọn ipè, lati jẹ ki gbogbo
wọn mura; ṣugbọn kò si ẹnikan ti o lọ
si ogun: nitori ibinu mi wà lori gbogbo
wọn.
15 Idà mbẹ lode, ajakálẹ àrun ati iyàn
si mbẹ ninu: ẹniti o wà li oko yio kú nipa
idà; ẹniti o wà ninu ilu, ìyàn ati ajakálẹ
àrun ni yio si jẹ ẹ run.
16 Ṣugbọn awọn ti o bọ́ ninu wọn yio
salà, nwọn o si wà lori oke bi adabà afoni-
foji, gbogbo nwọn o ma gbãwẹ, olukuluku
nitori aiṣedede rẹ̀.
17 Gbogbo ọwọ́ ni yio rọ, gbogbo ẽkun
ni yio si di ailera bi omi.

Digitized by Google

18 Aṣọ ọ̀fọ ni nwọn o fi gbajá pẹlu;
ìbẹru ikú yio si bò wọn mọlẹ; itiju yio si
wà loju gbogbo wọn, ẽpá yio si wà li ori
gbogbo wọn.
19 Nwọn o sọ fadaka wọn si igboro,
wura wọn li a o si mu kuro; fadaka wọn
ati wura wọn kì yio si le gbà wọn là li ọjọ
ibinu Oluwa: nwọn kì yio tẹ́ ọkàn wọn
lọrùn, bẽni nwọn kì yio kún inu wọn; ni-
tori on ni idùgbolu aiṣedede wọn.
20 Bi o ṣe ti ẹwà ohun ọṣọ́ rẹ̀ ni, o gbe
e ka ibi ọlanla: ṣugbọn nwọn yá ere irira
wọn ati ohun ikorira wọn ninu rẹ̀: nitorina
li emi ṣe mu u jina si wọn.
21 Emi o si fi i si ọwọ́ awọn alejo fun
ijẹ, ati fun enia buburu aiye fun ikogun:
nwọn o si bà a jẹ.
22 Oju mi pẹlu li emi o yipada kuro
lọdọ wọn, nwọn o si ba ibi ikọkọ mi jẹ;
nitori awọn ọlọṣà yio wọ inu rẹ̀, nwọn o si
bà a jẹ.
23 Rọ ẹ̀wọn kan; nitori ilẹ na kún fun
ẹ̀ṣẹ ẹjẹ, ilu-nla na si kún fun iwa-ipa.
24 Nitorina li emi o mu awọn keferi ti o
burujulọ, nwọn o si jogun ile wọn: emi o
si mu ọṣọ-nla awọn alagbara tán pẹlu, ibi
mimọ́ wọn li a o si bajẹ.
25 Iparun mbọ̀ wá, nwọn o si wá alafia,
kì yio si si.
26 Tulasì yio gori tulasìn, irọkẹ̀kẹ yio si
gori irọkẹ̀kẹ; nigbana ni nwọn o bere lọdọ
woli; ṣugbọn ofin yio ṣegbé kuro lọdọ alufa,
ati imọ̀ kuro lọdọ awọn agbà.
27 Ọba yio ṣọ̀fọ, a o si fi idahoro wọ̀
ọmọ-alade, ọwọ́ awọn enia ilẹ na li a o wa-
hala, emi o ṣe si wọn gẹgẹ bi ọ̀na wọn, ati
gegẹ bi ẹjọ wọn ti ri li emi o dá a fun wọn:
nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.

ORI 8.

O SI ṣe, li ọdun ẹkẹfa, li oṣù ẹkẹfa, li ọjọ
karun oṣù, bi mo ti joko ni ile mi, ti
awọn àgbagba Juda si joko niwaju mi, ni
ọwọ́ Oluwa Ọlọrun bà le mi nibẹ.
2 Nigbana ni mo wò, si kiye si i, aworán
bi irí iná: lati irí ẹgbẹ rẹ̀ ani de isalẹ, iná;
ati lati ẹgbẹ́ rẹ de oke, bi irí didan bi àwọ
amberi.
3 O si nà àworan ọwọ́ jade, o si mu mi
ni ìdi-irun ori mi; ẹmi si gbe mi soke lagbe-
demeji aiye on ọrun, o si mu mi wá ni iran
Ọlọrun si Jerusalemu, si ilẹkun ẹnu-ọ̀na ti
inu to kọju si ariwa; nibiti ijoko ere owu
wà ti nmu ni jowu.
4 Si kiyesi i, ogo Ọlọrun Israeli wà nibẹ,
gẹgẹ bi iran ti mo ri ni pẹtẹlẹ.
5 Nigbana li o wi fun mi pe, Ọmọ enia,
gbe oju rẹ soke nisisiyi si ihà ọ̀na ariwa.
Bẽni mo gbe oju mi soke si ọna ihà ariwa,
si kiye si i, ere owu yi niha ariwa li ati-
wọ̀le ọ̀na pẹpẹ.
6 Pẹlupẹlu o wi fun mi pe, Ọmọ enia,
iwọ ri ohun ti nwọn nṣe? ani irira nla ti
ile Israeli nṣe nihinyi, ki emi ba le lọ jina
kuro ni ibi mimọ́ mi? ṣugbọn si tun yipa-
da, iwọ o si ri ohun irira ti o jù wọnyi lọ.
7 O si mu mi wá si ẹna-ọ̀na agbala; ni-
gbati mo si wò, kiye si i iho lara ogiri.
8 Nigbana li o wi fun mi pe, Ọmọ enia,
dá ogirí na lu nisisiyi: nigbati mo si ti dá
ogiri na lu tan, kiye si i, ilẹkun.
9 O si wi fun mi pe, Wọ ile, ki o si wo
ohun irira buburu ti nwọn nṣe nihin.
10 Bẽni mo wọle, mo si ri; si kiye si i,
gbogbo aworan ohun ti nrakò, ati ẹranko
irira, ati gbogbo oriṣa ile Israeli li a yá li
aworan lara ogiri yika kiri.
11 Adọrin ọkọnrin ninu awọn agbà ile
Israeli si duro niwaju wọn, Jaasania ọmọ
Ṣafani si duro lãrin wọn, olukuluku pẹlu
awo turari lọwọ rẹ̀; ẽfin ṣiṣu dùdu ti turari
si goke lọ.
12 Nigbana li o si wi fun mi pe, Ọmọ
enia iwọ ri ohun ti awọn agbà ile Israeli
nṣe li okunkùn, olukuluku ninu iyará oriṣa
tirẹ̀? nitori nwọn wipe, Oluwa kò ri wa;
Oluwa ti kọ̀ aiye silẹ.
13 O si wi fun mi pe, Tun yipada, iwọ o
si ri ohun irira ti o tobi jù yi ti nwọn nṣe.
14 Nigbana li o mu mi wá si ilẹkun ẹnu-
ọ̀na ile Oluwa, ti o wà nihà ariwa; si kiye
si i, awọn obirin joko nwọn nsọkun fun
Tammusi.
15 Nigbana li o sọ fun mi pe, Iwọ ri eyi,
Iwọ ọmọ enia? tun yipada, iwọ o si ri
ohun irira ti o tobi ju wọnyi lọ.
16 O si mu mi wá si inu agbala ile Olu-
wa, si kiye si i, li ẹnu-ọ̀na tempili Oluwa,
lãrin iloro ati pẹpẹ, ni iwọ̀n ọkọnrin mẽdọ-
gbọ̀n wà, ti nwọn kẹ̀hin si tẹmpili Oluwa,
ti nwọn si kọju si ila-õrùn; nwọn si fori-
balẹ fun õrun si ila-õrun.
17 Nigbana li o wi fun mi pe, Iwọ ri eyi,
ọmọ enia? ohun kekere ni fun ile Juda lati
ṣe ohun irira ti nwọn nṣe nihin? nitori
nwọn fi ìwa-ipa kún ilẹ na, nwọn si ti pada
lati mu mi binu, si kiye si i, nwọn tẹ̀ ẹka-
igi bọ imú wọn.
18 Emi pẹlu yio si fi irúnu ba wọn lò:
oju mi kì yio dasi, bẽli emi kì yio ṣãnu:
ati bi o tilẹ ṣepe nwọn fi ohùn rara kigbe
li eti mi, sibẹ emi kì yio gbọ́ ti wọn.

Digitized by Google

## ORI 9.

OSI fi ohùn rara kigbe li eti mi wipe, Mu gbogbo awọn alaṣẹ ilu sunmọ itosi, olukuluku ton ti ohun ija iparun li ọwọ́ rẹ̀.

2 Si kiyesi i, ọkọnrin mẹfa jade lati ẹnu ilẹkun oke wá, ti o wà niha ariwa, olukuluku ton ti ohun-ijà ipani li ọwọ́ rẹ̀: ọkọnrin kan ninu wọn si wọ aṣọ ọgbọ̀, pẹlu ìwo-tàdawa akọwe li ẹgbẹ́ rẹ̀; nwọn si wọ inu ile, nwọn si duro lẹba pẹpẹ idẹ.

3 Ogo Ọlọrun Israeli si ti goke kuro lori kerubu, eyi ti o ti wà, si iloro ile. O si pè ọkọnrin na ti o wọ aṣọ ọgbọ̀, ti o ni ìwo-tàdawa akọwe li ẹgbẹ́ rẹ̀:

4 Oluwa si wi fun u pe, La ãrin ilu já, li ãrin Jerusalemu, ki o si sami si iwaju awọn ọkọnrin ti nkẹdùn, ti nwọn si nkigbe nitori ohun irira ti nwọn nṣe lãrin rẹ̀.

5 O si sọ fun awọn iyokù li eti mi, pe, Ẹ tẹ̀ le e la ilu lọ, ẹ si ma kọlù: ẹ má jẹ ki oju nyin dasi, bẹni ẹ máṣe ṣãnu.

6 Ẹ pa arugbo ati ọmọde patapata, awọn wundia ati ọmọ kekeke ati obirin; ṣugbọn ẹ máṣe sunmọ ẹnikan lara ẹniti àmi na wà; ẹ si bẹrẹ lati ibi mimọ́ mi. Bẽni nwọn bẹrẹ lati ọdọ awọn agbà ti o wà niwaju ile.

7 O si wi fun wọn pe, ẹ sọ ile na di aimọ́, ẹ si fi okú kún agbala na: ẹ jade lọ. Nwọn si jade lọ, nwọn si pa enia ni ilu.

8 O si ṣe, nigbati nwọn npa wọn, ti a si fi emi silẹ, mo da oju mi bo ilẹ, mo si kigbe, mo si wipe, Oluwa Ọlọrun, iwọ o ha pa gbogbo awọn iyokù Israeli run, nipa dida irúnu rẹ jade sori Jerusalemu?

9 O si wi fun mi pe, Aiṣedede ile Israeli ati ti Juda pọ̀ gidigidi, ilẹ na si kún fun ẹjẹ, ilu si kún fun iyi-ẹjọ-po, nitori nwọn wipe, Oluwa ti kọ aiye silẹ, Oluwa kò riran.

10 Bi o si ṣe ti emi ni, oju mi kì o dasi, bẹ̃li emi kì o ṣanu, ṣugbọn emi o sán ọ̀na wọn pada si ori wọn.

11 Si kiye si i, ọkọnrin ti o wọ aṣọ ọ̀gbọ, ti o ni ìwo-tadawa li ẹgbẹ́ rẹ̀ rohìn, wipe, mo ti ṣe gẹgẹ bi o ti paṣẹ fun mi.

## ORI 10.

MO si wò, si kiye si i, ninu ofurufu ti o wà loke lori awọn kerubu, ohun kan hàn li ori wọn bi okuta safire bi irí aworan itẹ́.

2 O si sọ fun ọkọnrin ti o wọ aṣọ ọ̀gbọ, o si wipe, Bọ sarin kẹkẹ, labẹ kerubu; si bu ikúnwọ ẹyin iná lati agbedemeji awọn kerubu; si fọ́n wọn ka sori ilu na. O si wọ inu ile li oju mi.

3 Awọn kerubu si duro li apá ọtun ile na, nigbati ọkọnrin na wọ ile; awọsanma si kún agbala ti inu.

4 Ogo Oluwa si goke lọ kuro lori kerubu o si duro loke iloro ile na; ile na si kún fun awọsanma, agbala na si kún fun didàn ogo Oluwa.

5 A si gbọ́ iró iyẹ awọn kerubu titi de agbala ode, bi ohùn Ọlọrun Oludumare nigbati o nsọ̀rọ.

6 O si ṣe, nigbati a ti paṣẹ fun ọkọnrin ti o wọ aṣọ ọgbọ, wipe, Fọn iná lati ãrin awọn kẹkẹ, lati ãrin awọn kerubu, o si wọ inu ile, o si duro lẹba awọn kẹkẹ.

7 Kerubu kan si nà ọwọ́ rẹ̀ jade lati ãrin awọn kerubu si iná ti o wà li ãrin awọn kerubu, o si mu ninu rẹ, o si fi si ọwọ́ ẹniti o wọ aṣọ ọgbọ̀: ẹniti o gbà a; ti o si jade lọ.

8 Aworan ọwọ́ enia si hàn ninu awọn kerubu labẹ iyẹ́ wọn.

9 Nigbati mo si wò, kiye si i, awọn kẹkẹ mẹrin na niha awọn kerubu, kẹkẹ kan niha kerubu kan, ati kẹkẹ miran niha kerubu miran; irí awọn kẹkẹ na si dabi awọ̀ okuta berili.

10 Bi o si ṣe ti irí wọn, awọn mẹrẹrin ni aworan kanna, bi ẹnipe kẹkẹ́ kan ti wà li ãrin kẹkẹ́ kan.

11 Nigbati nwọn lọ, nwọn fi ihà wọn mẹrẹrin lọ, nwọn kò yipada bi nwọn ti nlọ, ṣugbọn ibi ti ori ba kọju si, nwọn a tẹle e; nwọn kò yipada bi nwọn ti nlọ.

12 Ati gbogbo ara wọn, ati ẹhìn wọn, ati ọwọ́ wọn ati iyẹ́ wọn, ati awọn kẹkẹ́, kún fun oju yika kiri kẹkẹ́, ti awọn mẹrẹrin ni.

13 Niti awọn kẹkẹ́, a ke si wọn li etí mi wipe, Kẹkẹ́!

14 Olukuluku wọn si ni oju mẹrin, oju ekini oju kerubu, oju keji oju enia, ati ẹkẹta oju kiniun, ati ẹkẹrin oju idi.

15 A si gbe awọn kerubu soke, eyi ni ẹda alãye ti mo ri lẹba ọdọ̀ Kebari.

16 Nigbati awọn kerubu si lọ, awọn kẹkẹ lọ li ẹgbẹ́ wọn: nigbati awọn kerubu si gbe iyẹ́ wọn soke lati fò soke kuro lori ilẹ, kẹkẹ́ kanna kò yipada kuro li ẹgbẹ́ won.

17 Nigbati nwọn duro, wọnyi duro; nigbati a si gbe wọn soke, wọnyi gbe ara wọn soke pẹlu; nitori ẹmi ẹda alãye na mbẹ ninu wọn.

18 Ogo Oluwa si lọ kuro ni iloro ile na, o si duro lori awọn kerubu.

Digitized by Google

19 Awọn kerubu si gbe iyẹ́ wọn soke,
nwọn si fò kuro lori ilẹ li oju mi: nigbati
nwọn jade lọ, awọn kẹkẹ wà li ẹgbẹ̀ wọn
pẹlu, olukuluku si duro nibi ilẹkun ẹnu-
ọna ilà-õrun ile Oluwa: ogo Ọlọrun
Israeli si wà lori wọn loke.
20 Eyi ni ẹda alãye ti mo ri labẹ Ọlọrun
Israeli li ẹba odò Kebari, mo si mọ̀ pe
kerubu ni nwọn.
21 Olukuluku wọn ni oju mẹrin li ọkan-
kan, olukuluku wọn si ni iyẹ́ mẹrin; ati
aworan ọwọ́ enia wà li abẹ iyẹ́ wọn.
22 Aworan oju wọn si jẹ oju kanna ti
mo ri lẹba odò Kebari, iri wọn ati awọn
tikara wọn: olukuluku wọn lọ li ọkankan
ganran.

## ORI 11.

EMI si gbe mi soke, o si mu mi wá si
ẹnu-ọ̀na ile Oluwa ti ilà-õrun ti o kọju
siha ilà-õrùn, si kiyesi i, ọkọnrin mẹdọ-
gbọn wà nibi ilẹkun ẹnu-ọ̀na; ninu awọn
ẹniti mo ri Jaasania ọmọ Assuri, ati Pelatia
ọmọ Benaia, awọn ijoyè awọn enia.
2 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, awọn
ọkọnrin ti npete ikà ni wọnyi, ti nsi gbimọ̀
buburu ni ilu yi:
3 Awọn ti o wipe, Kò sunmọ tosi; ẹ jẹ
ki a kọ ile: ilu yi ni ìgba, awa si ni ẹran.
4 Nitorina sọtẹlẹ si wọn, Ọmọ enia,
sọtẹlẹ.
5 Ẹmi Oluwa si bà le mi, o si wi fun mi
pe, Sọ̀rọ; Bayi li Oluwa wi; Bayi li ẹnyin
ti wi, Ile Israeli, nitoriti mo mọ̀ olukuluku
ohun ti o wá si inu nyin.
6 Ẹnyin ti sọ okú nyin di pupọ̀ ni ilu yi,
ẹnyin si ti fi okú kún igboro rẹ̀,
7 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi,
Awọn okú nyin ti ẹnyin ti tẹ́ si ãrin rẹ̀,
awọn ni ẹran, ilu yi si ni ìgba; ṣugbọn
emi o mu nyin jade kuro lãrin rẹ̀.
8 Oluwa Ọlọrun wipe, Ẹnyin ti bẹ̀ru idà,
emi o si mu idà wa sori nyin.
9 Emi o si mu nyin kuro lãrin rẹ̀, emi o
si fi nyin le awọn alejo lọwọ, emi o si mu
idajọ ṣẹ si nyin lara.
10 Nipa idà li ẹnyin o ṣubu; emi o ṣe
idajọ nyin li agbegbe Israeli; ẹnyin o si
mọ̀ pe emi li Oluwa.
11 Ilu yi ki yio ṣe ìgba fun nyin, bẹ̃ni
ẹnyin kì yio jẹ ẹran lãrin rẹ̀; ṣugbọn emi o
ṣe idajọ nyin li agbegbe Israeli.
12 Ẹnyin o si mọ̀ pe emi li Oluwa: ni-
toriti ẹnyin kò rìn ninu aṣẹ mi, bẹ̃ni ẹnyin
kò mu idajọ mi ṣẹ, ṣugbọn ẹnyin ti hu ìwa
awọn keferi ti o wà yi nyin ka.
13 O si ṣe, nigbati mo sọtẹlẹ, Pelatia
ọmọ Benaiah kú. Mo si dojubolẹ, mo si fi
ohùn rara kigbe, mo si wipe, A! Oluwa
Ọlọrun, iwọ o ha ṣe aṣetan iyokù Israeli
bi?
14 Ọ̀rọ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
15 Ọmọ enia, awọn ará rẹ, ani awọn ará
rẹ, awọn ọkọnrin ninu ibatan rẹ, ati gbogbo
ile Israeli patapata, ni awọn ti awọn ara
Jerusalemu ti wi fun pe, Ẹ jina si Oluwa;
awa ni a fi ilẹ yi fun ni ini.
16 Nitorina wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun
wi, Bi mo tilẹ ti tá wọn nù réré lãrin awọn
keferi; bi mo si ti tú wọn ka lãrin ilẹ pupọ,
sibẹ emi o jẹ ibi mimọ́ kekere fun wọn ni
ilẹ ti wọn o de.
17 Nitorina wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun
wi, pe, Emi tilẹ kó nyin kuro lọdọ awọn
orilẹ-ède; emi o si kó nyin jọ lati ilẹ ti a ti
tú nyin ká si, emi o si fun nyin ni ilẹ Israeli.
18 Nwọn o si wá sibẹ, nwọn o si mu
gbogbo ohun irira rẹ̀ ati gbogbo ohun ẽri rẹ̀
kuro nibẹ.
19 Emi o si fun wọn li ọkàn kan, emi o
si fi ẹmi titun sinu nyin; emi o si mu ọkàn
okuta kuro lara wọn, emi o si fun wọn li
ọkàn ẹran:
20 Ki wọn le rìn ninu aṣẹ mi, ki wọn si
le pa ilana mi mọ, ki nwọn si ṣe wọn:
nwọn o si jẹ enia mi, emi o si jẹ Ọlọrun wọn.
21 Ṣugbọn bi o ṣe ti awọn ti ọkàn wọn
nrìn nipa ọkàn ohun irira ati ohun ẽri wọn,
Emi o sẹsan ọ̀na wọn sori ara wọn, li
Oluwa Ọlọrun wi.
22 Awọn kerubu si gbe iyẹ́ wọn soke,
pẹlu awọn kẹkẹ́ lẹgbẹ wọn, ogo Ọlọrun
Israeli si wà lori wọn loke.
23 Ogo Oluwa si goke lọ kuro lãrin ilu
na; o si duro lori oke-nla, ti o wà nihà ila-
õrùn ilu na.
24 Lẹhin na ẹmi gbe mi soke, o si mu
mi wá si Kaldea li ojuran, nipa Ẹmi
Ọlọrun sọdọ awọn ti igbekun. Bẹ̃ni iran ti
mo ti ri lọ kuro lọdọ mi.
25 Mo si sọ gbogbo ohun ti Oluwa ti fi
hàn mi fun awọn ti igbekùn.

## ORI 12.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, iwọ ngbe ãrin ọlọ̀tẹ ile,
ti nwọn ni oju lati ri, ti kò si ri; nwọn
ni eti lati gbọ́, nwọn kò si gbọ́: nitori
ọlọ̀tẹ ile ni nwọn.
3 Nitorina, iwọ ọmọ enia, mura nkan
kikolọ, ki o si kó lọ li oju wọn li ọsan; ki
o si kó lati ipò rẹ lọ si ibomiran li oju wọn;

Digitized by Google

o le ṣe pe nwọn o ronu, bi nwọn tilẹ jẹ
ọlọ̀tẹ ile.
4 Ki o si mu nkan 'rẹ jade li ọsan li oju
wọn, bi nkan kikolọ; ki o si jade lọ li
aṣalẹ li oju wọn, bi awọn ti nlọ si igbekùn.
5 Da ogiri lu loju wọn, ki o si kó jade
nibẹ.
6 Li oju wọn ni ki o rù u le ejika rẹ, ki
o si rù u lọ ni wiriwiri alẹ, ki o si bo oju rẹ,
ki o má ba ri ilẹ: nitori mo ti gbe ọ kalẹ
fun àmi si ile Israeli.
7 Mo si ṣe bi a ti paṣẹ fun mi: mo mu
nkan mi jade li ọsan, bi nkan fun igbekùn,
mo si fi ọwọ́ mi dá ogiri lu li aṣalẹ; mo
gbe e jade ni wiriwiri alẹ, mo si rù u le
ejika mi loju wọn.
8 Li owurọ ọ̀rọ Oluwa si ti tọ̀ mi wá,
wipe,
9 Ọmọ enia, ile Israeli, ọlọ̀tẹ ile nì kò ti
wi fun ọ pe, kini iwọ nṣe?
10 Wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa Ọlọ-
run wi; Ẹrù yi hàn fun awọn ọmọ-alade
ni Jerusalemu, ati gbogbo ile Israeli ti o
wà lãrin wọn.
11 Wipe, emi ni àmi nyin, gẹgẹ bi mo ti
ṣe, bẹ̃ni a o si ṣe si wọn: nwọn o ko kuro,
nwọn o si lọ si igbekùn.
12 Ọmọ-alade ti o wà larin wọn yio si
rẹrù lori ejika rẹ̀ ni wiriwiri alẹ, yio si jade
lọ; nwọn o si dá ogiri lu lati kó jade nibẹ;
yio si bo oju rẹ̀, ki o má ba fi oju rẹ̀ ri ilẹ.
13 Àwọ̀n mi ni emi o si tẹ́ le e lori, a o
si mu u ninu ẹgẹ́ mi: emi o si mu u wá si
Babiloni, si ilẹ awọn ara Kaldea; kì yio si
ri i, bẹ̃ni yio kú nibẹ.
14 Gbogbo awọn ti o yi i ka lati ràn a
lọwọ, ati gbogbo ọwọ-ogun rẹ̀, ni emi o
tuká si gbogbo afẹ̃fẹ, emi o si yọ idà le wọn.
15 Nwọn o si mọ̀ pe, Emi li Oluwa,
nigbati mo ba tú wọn ka lãrin awọn orilẹ-
ède; ti mo ba si fọ́n wọn ká ilẹ pupọ.
16 Ṣugbọn emi o kù diẹ ninu wọn silẹ
lọwọ idà, lọwọ iyàn, ati lọwọ ajakálẹ arùn;
ki nwọn le sọ gbogbo ohun ẽri wọn lãrin
awọn keferi, nibiti nwọn ba de; nwọn o si
mọ̀ pe emi li Oluwa.
17 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
18 Ọmọ enia, fi ìgbọnriri jẹ onjẹ rẹ, si fi
ìwariri ati ikiyesara mu omi rẹ;
19 Ki o si sọ fun awọn enia ilẹ na pe,
Bayi li Oluwa Ọlọrun wi fun awọn ara
Jerusalemu, niti ilẹ Israeli; nwọn o fi
ikiyesara jẹ onjẹ wọn, nwọn o si fi iyanu
mu omi wọn, ki ilẹ rẹ̀ ki o le di ahoro kuro
ninu gbogbo ohun ti o wà ninu rẹ̀, nitori
iwa-ipá gbogbo awọn ti ngbe ibẹ̀.
20 Awọn ilu ti a ngbe yio di ofo, ilẹ na
yio si di ahoro; ẹnyin o si mọ̀ pe emi li
Oluwa.
21 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
22 Ọmọ enia, owe wo li ẹnyin ni, ni ilẹ
Israeli pe, A fà ọjọ gùn, gbogbo iran di
asan?
23 Nitorina wi fun wọn pe, Bayi li
Oluwa Ọlọrun wi; emi o jẹ ki owe yi
dẹkun, nwọn kì yio si pa a li owe ni Israeli
mọ; ṣugbọn wi fun wọn pe, Ọjọ kù si
dẹ̀dẹ; ati imuṣẹ gbogbo iran.
24 Nitori kì yio si iran asan mọ, kì yio
si si afọṣe ti npọnni ninu ile Israeli.
25 Nitori emi li Oluwa: emi o sọ̀rọ, ọ̀rọ
ti emi o sọ yio si ṣẹ, a kì yio fà a gùn mọ;
nitori li ọjọ nyin, Ọlọtẹ ilẹ, li emi o sọ ọ̀rọ
na, emi o si ṣe e, ni Oluwa Ọlọrun wi.
26 Ọ̀rọ Oluwa si tun tọ̀ mi wá, wipe,
27 Ọmọ enia, kiyesi i, awọn ara ile Is-
raeli wipe, Iran ti o ri, fun ọjọ pupọ ti
mbọ̀ ni, o si sọ asọtẹlẹ akoko ti o jina rere.
28 Nitorina wi fun wọn pe, Bayi li Olu-
wa Ọlọrun wi: Kò si ọkan ninu ọ̀rọ mi ti
a o fà gùn mọ, ṣugbọn ọ̀rọ ti mo ti sọ yio
ṣẹ, ni Oluwa wi.

## ORI 13.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe.
2 Ọmọ enia sọtẹlẹ si awọn woli Israeli
ti nsọtẹlẹ, ki o si wi fun awọn ti nti ọkàn
ara wọn ṣọtẹlẹ pe, Ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa;
3 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, egbé ni fun
awọn aṣiwere woli, ti nwọn ntẹ̀le ẹmi ara
wọn, ti nwọn kò si ri nkan!
4 Israeli, awọn woli rẹ dabi kọ̀lọkọ̀lọ ni
ijù,
5 Ẹnyin kò ti goke lọ si ibi ti o ya,
bẹ̃ni ẹ kò si tun odi mọ fun ile Israeli lati
duro li oju ogun li ọjọ Oluwa.
6 Nwọn ti ri asan ati àfọṣẹ eke, pe,
Oluwa wi: bẹ̃ni Oluwa kò rán wọn, nwọn
si ti jẹ ki awọn ẹlomiran ni ireti pe, nwọn
o fi idí ọ̀rọ wọn mulẹ.
7 Ẹnyin kò ti ri iran asan, ẹ kò si ti fọ
àfọṣẹ eke, ti ẹnyin wipe, Oluwa wi bẹ̃?
bẹ̃ni emi kò sọrọ.
8 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Nitori ẹnyin ti sọ̀rọ asan, ẹnyin si ti ri eke,
nitorina, kiyesi i, mo dojukọ nyin, ni
Oluwa wi.
9 Ọwọ́ mi yio si wà lori awọn woli, ti
nwọn ri asan, ti nwọn si nfọ àfọṣẹ eke;
nwọn kì yio si ninu ijọ awọn enia mi, bẹ̃ni
a kì yio kọwe wọn sinu iwe ile Israeli;

Digitized by Google

bẹ̃ni nwọn kì yio wọ̀ ilẹ Israeli, ẹnyin o si
mọ̀ pe emi li Oluwa.
10 Nitori, ani nitori ti nwọn ti tàn awọn
enia mi wipe, Alafia; bẹ̃ni kò si alafia,
ọkan si mọ ogiri, si kiyesi, awọn miran si
nfi amọ̀ ti a kò pò rẹ́ ẹ.
11 Wi fun awọn ti nfi amọ̀ aipò rẹ́ ẹ, pe,
yio ṣubu; òjo yio rọ̀ pupọ; ati Ẹnyin,
yinyin nla, o si bọ́; ẹfũfu lile yio si ya a.
12 Kiyesi i, nigbati ogiri na ba wo, a kì
yio ha wi fun nyin pe, Rirẹ́ ti ẹnyin rẹ́ ẹ ha
dà?
13 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
emi o tilẹ fi ẹfũfu lile ya a ni irúnu mi;
òjo yio si rọ̀ pupọ ni ibinu mi, ati yinyin
nla ni irúnu mi lati run u.
14 Bẹ̃ni emi o wo ogiri ti ẹnyin fi amọ̀
aipò rẹ́ lulẹ, emi o si mu u wá ilẹ, tobẹ̃ ti
ipilẹ rẹ̀ yio hàn, yio si ṣubu, a o si run
nyin li ãrin rẹ̀: ẹnyin o si mọ̀ pe, emi li
Oluwa.
15 Bayi li emi o mu ibinu mi ṣẹ lori
ogiri na, ati lori awọn ti o fi amọ̀ aipò rẹ́ ẹ,
emi o si wi fun nyin pe, Ogiri na kò si mọ
ati awọn ti o ti rẹ́ ẹ;
16 Eyini ni, awọn woli Israeli, ti nwọn
sọtẹlẹ niti Jerusalemu, ti nwọn si ri iran
alafia fun u, bẹ̃ni alafia kò si, ni Oluwa
Ọlọrun wi.
17 Iwọ ọmọ enia, dojukọ awọn ọmọbirin
awọn enia rẹ bẹ̃ gẹgẹ, ti nwọn nsọtẹlẹ lati
ọkàn ara wọn wá; ki o si sọtẹlẹ si wọn,
18 Si wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi:
Egbé ni fun awọn obirin ti nrán tìmtim si
gbogbo ìgbọnwọ, ti nwọn si ndá gèle si ori
olukuluku enia lati ṣọdẹ ọkàn! Ẹnyin o
ṣọdẹ ọkàn awọn enia mi bi, ẹnyin ọ si gbà
ọkàn ti o tọ̀ nyin wá là bi?
19 Ẹnyin o ha si bà mi jẹ lãrin awọn
enia mi nitori ikunwọ ọkà bàba, ati nitori
òkele onjẹ, lati pa ọkàn ti kì ba kú, ati lati
gba awọn ọkàn ti kì ba wà lãye là, nipa
ṣiṣeke fun awọn enia mi ti ngbọ́ eke nyin?
20 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Kiyesi i, mo dojukọ awọn tìmtim nyin, ti
ẹnyin fi nṣọdẹ ọkàn nibẹ lati mu wọn fò,
emi o si yà wọn kuro li apá nyin, emi o si
jẹ ki awọn ọkàn na lọ, ani awọn ọkàn ti
ẹnyin ndọdẹ lati mu fò.
21 Gèle nyin pẹlu li emi o ya, emi o si
gba awọn enia mi lọwọ nyin, nwọn kì yio
si si lọwọ nyin mọ lati ma dọdẹ wọn; ẹnyin
o si mọ̀ pe emi li Oluwa.
22 Nitoripe eke li ẹnyin fi mu ọkàn
awọn olododo kãnu, awọn ẹniti emi kò mu
kãnu, ẹnyin si mu ọwọ́ enia buburu le, ki o
má ba pada kuro li ọ̀na buburu rẹ̀ nipa ṣiṣe
ileri ìye fun u:
23 Nitorina ẹnyin kì yio ri asan mọ, ẹ
kì yio si ma fọ àfọṣẹ, nitoriti emi o gba
awọn enia mi kuro li ọwọ́ nyin, ẹnyin o si
mọ̀ pe emi li Oluwa.

## ORI 14.

AWỌN kan ninu awọn àgba Israeli si wá
sọdọ mi, nwọn si joko niwaju mi.
2 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
3 Ọmọ enia, awọn ọkọnrin wọnyi ti gbe
oriṣa wọn si ọkàn wọn, nwon si fi ohun
ìdugbolu aiṣedede wọn siwaju wọn: emi o
ha jẹ ki nwọn bere lọwọ mi rara bi?
4 Nitorina sọ fun wọn, ki o si wi fun
wọn pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; oluku-
luku ọkọnrin ile Israeli ti o gbe oriṣa rẹ̀ si
ọkàn rẹ̀, ti o si fi ohun ìdugbolu aiṣedẽde
rẹ̀ siwaju rẹ̀, ti o si wá sọdọ woli; emi
Oluwa yio dá ẹniti o wá lohùn gẹgẹ bi ọpọ-
lọpọ oriṣa rẹ̀.
5 Ki emi ba le mu ile Israeli li ọkàn ara
wọn, nitori gbogbo wọn di ajeji si mi nipasẹ
oriṣa wọn.
6 Nitorina wi fun ile Israeli pe, Bayi li
Oluwa Ọlọrun wi; Ẹ ronupiwada, ki ẹ si
yipada kuro lọdọ oriṣa nyin, ki ẹ si yi oju
nyin kuro ninu ohun ẽri nyin.
7 Nitori olukuluku ninu ile Israeli, tabi
ninu alejo ti o ṣe atipo ni Israeli, ti o yà
ara rẹ̀ kuro lọdọ mi, ti o si gbe oriṣa rẹ̀ si
ọkàn rẹ̀, ti o si fi ohun ìdugbolu aiṣedẽde rẹ̀
siwaju rẹ̀, ti o si tọ̀ woli kan wá lati bere
lọwọ rẹ̀ niti emi: Emi Oluwa yio da a
lohùn tikalami:
8 Emi o si dojukọ ọkọnrin na, emi o si fi
i ṣe àmi ati owe, emi o si ké e kuro lãrin
awọn enia mi; ẹnyin o si mọ̀ pe, emi li
Oluwa.
9 Bi a ba si tan woli na jẹ nigbati o sọ
ohun kan, Emi Oluwa ni mo ti tan woli na
jẹ, emi o si nawọ mi le e, emi o si run u
kuro lãrin Israeli enia mi.
10 Awọn ni yio si rù ìya aiṣedẽde wọn;
ìya woli na yio ri gẹgẹ bi ìya ẹniti o bère
lọdọ rẹ̀.
11 Ki ile Israeli má ba ṣako lọ kuro lọdọ
mi mọ, ki nwọn má ba fi gbogbo irekọja
wọn bà ara wọn jẹ mọ, ṣugbọn ki nwọn ki
o le jẹ enia mi, ki emi si le jẹ Ọlọrun wọn,
ni Oluwa Ọlọrun wi.
12 Ọ̀rọ Oluwa si tun tọ̀ mi wá, wipe,
13 Ọmọ enia, nigbati ìlẹ na ba ṣẹ̀ si mi
nipa irekọja buburu, nigbana ni emi o
nawọ mi le e, emi o si ṣẹ́ ọpa onjẹ inu rẹ̀,

Digitized by Google

emi o si rán ìyan si i, emi o si ke enia ati
ẹranko kuro ninu rẹ̀ :
14 Bi awọn ọkọnrin mẹta wọnyi, Noa,
Danieli, ati Jobu tilẹ wà ninu rẹ̀, kiki ẹmi
ara wọn ni nwọn o fi ododo wọn gbàla, li
Oluwa Ọlọrun wi.
15 Bi mo ba jẹ ki ẹranko buburu kọja
lãrin ilẹ na, ti nwọn si bà a jẹ, tobẽ ti o di
ahoro, ti ẹnikan kò le là a ja nitori awọn
ẹranko na.
16 Bi awọn ọkọnrin mẹta wọnyi tilẹ wà
ninu rẹ̀, Oluwa Ọlọrun wipe, Bi mo ti wà,
nwọn kì yio gbà ọmọkọnrin tabi ọmọbirin
là ; awọn nikan li a o gbàla, ṣugbọn ilẹ na
yio di ahoro.
17 Tabi bi mo mu idà wá sori ilẹ na, ti
mo si wipe, Idà, la ilẹ na ja ; tobẽ ti mo ke
enia ati ẹranko kuro ninu rẹ̀ :
18 Bi awọn ọkọnrin mẹta yi tilẹ wà ninu
rẹ̀, Oluwa Ọlọrun wipe, Bi mo ti wà, nwọn
kì yio gba ọmọkọnrin tabi ọmọbirin. là,
ṣugbọn awọn tikara wọn nikan li a o gbàla.
19 Tabi bi mo rán ajàkalẹ arùn si ilẹ na,
ti mo si da irúnu mi le e ni ẹjẹ, lati ke enia
ati ẹranko kuro ninu rẹ̀ :
20 Bi Noa, Danieli, ati Jobu tilẹ wà
ninu rẹ̀, Oluwa Ọlọrun wipe, Bi mo ti wà,
nwọn kì yio gba ọmọkọnrin tabi ọmọbirin
là ; kìki ọkàn ara wọn ni awọn o fi ododo
wọn gbàla.
21 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun wi ;
Melomelo ni nigbati mo ba rán awọn idajọ
kikan mi mẹrẹrin sori Jerusalemu, idà, ati
ìyàn, ati ẹranko buburu, ati ajakalẹ àrun,
lati ké enia ati ẹranko kuro ninu rẹ̀ ?
22 Ṣugbọn kiye si i, ninu rẹ̀ li a o kù
awọn ti a o yọ silẹ, ti a o mu jade wá, ati
ọmọkọnrin, ati ọmọbirin, kiye si i, nwọn o
jade tọ̀ nyin wá, ẹnyin o si ri ọ̀na wọn ati
iṣe wọn, a o si tù nyin ninu niti ibi ti emi
ti mu wá sori Jerusalemu, ani niti gbogbo
ohun ti mo ti mu wá sori rẹ̀.
23 Nwọn o si tù nyin ninu, nigbati
ẹnyin ba ri ọ̀na wọn ati iṣe wọn : ẹnyin o
si mọ̀ pe emi kò ṣe gbogbo ohun ti mo ti ṣe
ninu rẹ̀ li ainidi, ni Oluwa Ọlọrun wi.

## ORI 15.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, kini igi ajara fi ju igiki-
gi lọ, tabi ju ẹka ti o wà lãrin igi igbo.
3 A ha le mu igi lara rẹ̀ ṣe isẹkiṣẹ ? tabi
enia le mu ẽkàn lara rẹ̀ lati fi ohunkohun
kọ́ sori rẹ̀.
4 Kiyesi i, a jù u sinu iná bi igi, iná si
jo ipẹkun rẹ̀ mejeji, ãrin rẹ̀ si jona. O ha
yẹ fun iṣẹkiṣẹ bi ?
5 Kiyesi i, nigbati o wà li odidi, kò yẹ
fun iṣẹ kan : melomelo ni kì yio si yẹ fun
iṣẹkiṣẹ, nigbati iná ba ti jo o, ti o si jona ?
6 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi ; Bi
igi ajara lãrin igi igbó, ti mo ti fi fun iná
bi igi, bẽni emi o fi ara Jerusalemu ṣe.
7 Emi o si doju mi kọ wọn, nwọn o jade
kuro ninu iná kan, iná miran yio si jo wọn,
ẹnyin o si mọ̀ pe emi li Oluwa, nigbati mo
ba dojukọ wọn.
8 Emi o si sọ ilẹ na di ahoro, nitori ti
nwọn ti dẹṣẹ, ni Oluwa Ọlorun wi.

## ORI 16.

ỌRỌ Oluwa tún tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, jẹ ki Jerusalemu mọ̀
ohun irira rẹ̀.
3 Si wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi si
Jerusalemu ; Ibi rẹ ati ilẹ ibi rẹ ni ati ilẹ
Kenaani wá ; ará Amori ni baba rẹ, ará
Hiti si ni iyá rẹ.
4 Ati niti ìbi rẹ, a kò da ọ ni iwọ́ ni ijọ
ti a bi ọ, bẽni a kò wẹ̀ ọ ninu omi lati mu
ọ mọ́, a kò fi iyọ̀ pa ọ lara rara, bẽni a kò fi
ọja wé ọ rara.
5 Kò si oju ti o kãnu fun ọ, lati ṣe ọkan
ninu nkan wọnyi fun ọ, lati ṣe iyọnu si ọ ;
ṣugbọn ninu igbẹ li a gbe ọ sọ si, fun iko-
rira ara rẹ, ni ijọ ti a bi ọ.
6 Nigbati mo si kọja lọdọ rẹ, ti mo si ri
ọ, ti a tẹ̀ ọ mọlẹ ninu ẹjẹ ara rẹ, mo wi fun
ọ nigbati iwọ wà ninu ẹjẹ rẹ pe, Yè : nitõ-
tọ, mo wi fun ọ nigbati iwọ wà ninu ẹjẹ rẹ
pe, Yè.
7 Emi ti mu ọ bi si i bi irudi itàna ìgbẹ;
iwọ si ti pọ̀ si i, o si ti di nla, iwọ si gbà
ohun ọṣọ́ ti o ti inu ọṣọ́ wá : a ṣe ọmú rẹ
yọ, irun rẹ si dagba, nigbati o jẹ pe iwọ ti
wà nihoho ti o si wà goloto.
8 Nigbati mo si kọja lọdọ rẹ, ti mo si
wò ọ ; kiye si i, ìgba rẹ jẹ ìgba ifẹ ; mo si
nà aṣọ mi bò ọ, mo si bo ihoho rẹ : nitõtọ,
mo bura fun ọ, mo si ba ọ da majẹmu, ni
Oluwa Ọlọrun wi, iwọ si di temi.
9 Nigbana ni mo fi omi wẹ̀ ọ ; nitõtọ,
mo wẹ ẹjẹ rẹ kuro lara rẹ patapata, mo si
fi ororo kùn ọ lara.
10 Mo wọ̀ ọ laṣọ oniṣẹ-ọnà pẹlu, mo si fi
awọ̀ badgeri wọ̀ ọ ni bàta, mo si fi aṣọ ọ̀gbọ
daradara di ọ ni amure yika, mo si fi aṣọ
ṣẹ́dà bò ọ.
11 Mo fi ohun-ọṣọ ṣe ọ lọṣọ pẹlu, mo si
fi júfu bọ̀ ọ lọwọ, mo si fi ẹ̀wọn kọ́ ọ li ọrùn.

Digitized by Google

12 Mo si fi oruka si ọ ni imú, mo si fi
oruka bọ̀ ọ leti, mo si fi ade daradara de ọ
lori.
13 Bayi ni a fi wura ati fadaka ṣe ọ
lọṣọ; aṣọ rẹ si jẹ ọgbọ̀ daradara, ati ṣẹ́dá,
ati aṣọ oniṣẹ-ọnà; iwọ jẹ iyẹfun daradara
ati oyin, ati ororo: iwọ si ni ẹwà gidigidi,
iwọ si gbilẹ di ijọba kan.
14 Okiki rẹ si kan lãrin awọn keferi
nitori ẹwà rẹ: nitori iwọ pé nipa ẹwà mi,
ti mo fi si ọ lara, ni Oluwa Ọlọrun wi.
15 Ṣugbọn iwọ gbẹkẹle ẹwà ara rẹ, o si
huwa panṣaga nitori okìki rẹ, o si dà gbo-
gbo agbere rẹ sori olukuluku ẹniti nkọja:
tirẹ̀ ni.
16 Iwọ si mu ninu ẹwù rẹ, iwọ si fi aṣọ
alaràbarà ṣe ibi giga rẹ lọṣọ, o si hùwa pan-
ṣaga nibẹ: iru nkan bẹ̃ kì yio de, bẹ̃ni kì
yio ri bẹ̃.
17 Iwọ si mu ohun ọṣọ́ ẹlẹwà rẹ ninu
wura mi, ati ninu fadaka mi, ti mo ti fun
ọ, iwọ si ṣe àworán ọkọnrin fun ara rẹ, o si
fi wọn ṣe panṣaga,
18 Iwọ si mu ẹwù oniṣẹ-ọnà rẹ, o si fi bò
wọn: iwọ si gbe ororo mi ati turari mi
kalẹ niwaju wọn.
19 Onjẹ mi pẹlu ti mo ti fun ọ, iyẹfun
daradara, ati ororo, ati oyin, ti mo fi bọ́ ọ,
iwọ tilẹ gbe e kalẹ niwaju wọn fun õrùn
didùn: bayi li o si ri, ni Oluwa Ọlọrun wi.
20 Pẹlupẹlu iwọ ti mu awọn ọmọ rẹ
ọkọnrin ati awọn ọmọ rẹ obirin, ti iwọ ti
bi fun mi, awọn wọnyi ni iwọ si ti fi rubọ
si wọn lati jẹ. Ohun kekere ha ni eyi ninu
ìwa panṣaga rẹ,
21 Ti iwọ ti pa awọn ọmọ mi, ti o si fi
wọn funni lati mu wọn kọja lãrin iná fun
wọn?
22 Ati ni gbogbo ohun irira rẹ, ati pan-
ṣaga rẹ, iwọ kò ranti ọjọ ewe rẹ, nigbati
iwọ wà nihoho ti o si wà goloto, ti a si bà
ọ jẹ ninu ẹjẹ rẹ.
23 O si ṣe lẹhin gbogbo ìwa buburu rẹ,
(Egbe, egbe ni fun ọ! ni Oluwa Ọlọrun
wi;)
24 Ti iwọ si kọ́ ile giga fun ara rẹ, ti
iwọ si ṣe ibi giga ni gbogbo ita fun ara rẹ.
25 Iwọ ti kọ́ ibi giga rẹ ni gbogbo ikó-
rita, o si ti sọ ẹwà rẹ di ikorira, o si ti ya
ẹsẹ rẹ si gbogbo awọn ti nkọja, o si sọ
panṣaga rẹ di pupọ.
26 Iwọ ti ba awọn ara Egipti aladugbo
rẹ, ti o sanra ṣe agbere, o si ti sọ panṣaga
rẹ di pupọ, lati mu mi binu.
27 Kiye si i, emi si ti nawọ mi le ọ lori,
mo si ti bu onjẹ rẹ kù, mo si fi ọ fun ifẹ
awọn ti o korira rẹ, awọn ọmọbirin Filistia,
ti ìwa ifẹkufẹ rẹ tì loju.
28 Iwọ ti ba awọn ara Assiria ṣe panṣaga
pẹlu, nitori iwọ kò ni itẹlọrun; nitotọ, iwọ
ti ba wọn ṣe panṣaga, sibẹsibẹ kò si le tẹ́
ọ lọrùn,
29 Iwọ si ti sọ agbere rẹ di pupọ lati ilẹ
Kenaani de Kaldea; sibẹsibẹ eyi kò si tẹ́ ọ
lọrun nihinyi.
30 Oluwa Ọlọrun wipe, aiyà rẹ ti ṣe alai-
lera to, ti iwọ nṣe nkan wọnyi, iṣe agídi
panṣaga obirin;
31 Nitipe iwọ kọ́ ile giga rẹ ni gbogbo
ikoríta, ti o si ṣe ibi giga rẹ ni gbogbo ita;
iwọ kò si wa dabi panṣaga obirin, nitipe
iwọ gan ọ̀ya.
32 Ṣugbọn gẹgẹ bi aya ti o ṣe panṣaga, ti
o gbà alejo dipo ọkọ rẹ̀!
33 Nwọn nfi ẹbùn fun gbogbo awọn pan-
ṣaga, ṣugbọn iwọ fi ẹbùn rẹ fun gbogbo
awọn olufẹ rẹ, iwọ si ta wọn lọrẹ, ki nwọn
le tọ̀ ọ wá ni ihà gbogbo fun panṣaga rẹ.
34 Eyiti o yatọ si ti awọn obirin miran
si mbẹ ninu rẹ, ninu panṣaga rẹ, ti ẹnikan
kò tẹle ọ lati ṣe panṣaga: ati nitipe iwọ
ntọrẹ, ti a kò si tọrẹ fun ọ nitorina iwọ
yatọ.
35 Nitorina, iwọ panṣaga, gbọ́ ọ̀rọ
Oluwa:
36 Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; Nitoriti
a dà ẹgbin rẹ jade, ti a si ri ihoho rẹ nipa
panṣaga rẹ pẹlu awọn olufẹ rẹ, ati pẹlu
gbogbo oriṣa irira rẹ, ati nipa ẹjẹ awọn ọmọ
rẹ, ti iwọ fi fun wọn:
37 Si kiye si i, Emi o kó gbogbo awọn
olufẹ rẹ jọ, awọn ẹniti iwọ ti ba jaiye, ati
gbogbo awọn ti iwọ ti fẹ, pẹlu gbogbo awọn
ti iwọ ti korira; ani emi o gbá wọn jọ
kakiri si ọ, emi o si fi ihoho rẹ hàn wọn,
ki nwọn ki o le ri gbogbo ihoho rẹ.
38 Emi o si dá ọ lẹjọ, gẹgẹ bi a ti da
awọn obirin lẹjọ ti o ba igbeyawo jẹ ti nwọn
si ta ẹjẹ silẹ; emi o si fi ẹjẹ fun ọ, ni irúnu
ati ni ijowu.
39 Emi o si fi ọ le wọn lọwọ pẹlu, nwọn
o si wo ibi giga rẹ, nwọn o si wo ibi giga
rẹ palẹ: nwọn o si bọ aṣọ rẹ pẹlu, nwọn o
si gbà ohun ọṣọ rẹ didara, nwọn o si fi ọ
silẹ ni ihoho, ati ni goloto.
40 Nwọn o mu ẹgbẹ́ kan wá si ọ pẹlu,
nwọn o si sọ ọ li okuta, nwọn o si fi idà
wọn gún ọ yọ.
41 Nwọn o si fi iná kun gbogbo ile rẹ;
nwọn o si mu idajọ ṣẹ si ọ lara niwaju
obirin pupọ; emi o si jẹ ki o fi panṣaga rẹ
mọ, iwọ pẹlu kì yio si funni ni ọ̀ya mọ.

Digitized by Google

42 Bẽni emi o jẹ ki irúnu mi si ọ ki o dá,
owú mi yio si kuro lọdọ rẹ, emi o si dakẹjẹ,
emi kì yio si binu mọ.
43 Nitoripe iwọ kò ranti ọjọ ewe rẹ,
ṣugbọn o si mu mi kanra ninu gbogbo nkan
wọnyi; si kiye si i, nitorina emi pẹlu o san
ẹsan ọ̀na rẹ si ọ lori, ni Oluwa Ọlọrun wi:
iwọ kì yio si ṣe ifẹkufẹ yi lori gbogbo ohun
irira rẹ mọ.
44 Kiyesi i, olukuluku ẹniti npowe ni
yio powe yi si ọ, wipe, Bi iyá ti ri, bẽni
ọmọ rẹ̀ obirin.
45 Iwọ ni ọmọ iyá rẹ ti o kọ̀ ọkọ rẹ̀, ati
awọn ọmọ rẹ̀; iwọ ni arabirin awọn arabi-
rin rẹ, ti o kọ̀ awọn ọkọ wọn ati awọn ọmọ
wọn: ará Hiti ni iyá rẹ, ará Amori si ni
baba rẹ.
46 Ẹgbọn rẹ obirin si ni Samaria, on ati
awọn ọmọbirin rẹ ti ngbe ọwọ́ osì rẹ: ati
aburo rẹ obirin ti ngbe ọwọ́ ọ̀tun rẹ ni
Sodomu ati awọn ọmọ rẹ̀ obirin.
47 Ṣugbọn iwọ kò rin ni ọ̀na wọn, iwọ
kò si ṣe gẹgẹ bi irira wọn: ṣugbọn, bi
ẹnipe ohun kekere ni eyini, iwọ bajẹ jù
wọn lọ ni gbogbo ọ̀na rẹ.
48 Oluwa Ọlọrun wipe, Bi mo ti wà,
Sodomu arabirin rẹ, on, tabi awọn ọmọ rẹ̀
obirin kò ṣe gẹgẹ bi iwọ ti ṣe, iwọ ati awọn
ọmọ rẹ obirin.
49 Kiyesi i, ẹ̀ṣẹ Sodomu arabirin rẹ niyi,
irera, onjẹ ajẹyo, ati ọ̀pọlọpọ orayè wà ninu
rẹ̀, ati ninu awọn ọmọ rẹ̀ obirin; bẽni on
kò mu ọwọ́ talaka ati alaini lokun.
50 Nwọn si gberaga, nwọn si ṣe ohun
irira niwaju mi: nitorina ni mo mu wọn
kuro gẹgẹ bi mo ti ri pe o dara.
51 Bẽni Samaria kò dá abọ̀ ẹ̀ṣẹ rẹ: ṣu-
gbọn iwọ sọ ohun irira rẹ di pupọ jù wọn
lọ, o si ti da awọn arabirin rẹ lare ninu
gbogbo ohun irira rẹ ti iwọ ti ṣe.
52 Iwọ pẹlu, ti o ti da awọn arabirin rẹ
lẹbi, ru itiju ara rẹ, nitori ẹ̀ṣẹ rẹ ti iwọ ti
ṣe ni iṣe irira jù wọn lọ; awọn ṣe olododo
jù iwọ lọ; nitotọ, ki iwọ ki o dãmu pẹlu,
si ru itiju rẹ, nitipe iwọ dá awọn arabirin
rẹ lare.
53 Nigbati mo ba tun mu igbèkun wọn
wá, igbèkun Solomu ati awọn ọmọ rẹ̀ obirin,
pẹlu igbèkun Samaria ati awọn ọmọ rẹ̀
obirin, nigbana li emi o tun mu igbèkun
awọn onde rẹ wá lãrin wọn:
54 Ki iwọ ki o le ru itiju ara rẹ, ki o si
le dãmu ni gbogbo eyi ti o ti ṣe, nitipe iwọ
jẹ itunu fun wọn.
55 Nigbati awọn arabirin rẹ Sodomu, ati
awọn ọmọ rẹ̀ obirin, ba pada si ipò wọn
iṣaju, ti Samaria ati awọn ọmọ rẹ̀ obirin ba
pada si ipò wọn iṣaju, nigbana ni iwọ ati
awọn ọmọ rẹ obirin yio pada si ipò nyin
iṣaju.
56 Nitori ẹnu rẹ kò da orukọ Sodomu
arabirin rẹ li ọjọ irera rẹ,
57 Ki a to ri ìwa buburu rẹ, bi akoko ti
awọn ọmọbirin Siria gàn ọ, ati gbogbo
awọn ti o wà yi i ka, awọn ọmọbirin
Filistia ti o gàn ọ ka kiri.
58 Iwọ ti ru ifẹkufẹ rẹ ati ohun irira rẹ,
ni Oluwa wi.
59 Nitori bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; Emi
o tilẹ ba ọ lò gẹgẹ bi iwọ ti ṣe, ti iwọ ti gàn
ibura nipa biba majẹmu jẹ.
60 Ṣugbọn emi o ranti majẹmu mi pẹlu
rẹ, ni ọjọ ewe rẹ, emi o si gbe majẹmu
aiyeraiye kalẹ fun ọ.
61 Iwọ o si ranti ọ̀na rẹ, oju o si tì ọ,
nigbati iwọ ba gba awọn arabirin rẹ, ẹgbọ́n
rẹ ati aburò rẹ: emi o si fi wọn fun ọ bi
ọmọbirin, ṣugbọn ki iṣe nipa majẹmu rẹ.
62 Emi o si gbe majẹmu mi kalẹ pẹlu
rẹ; iwọ o si mọ̀ pe emi li Oluwa.
63 Ki iwọ ki o le ranti, ki o si le dãmu,
ki iwọ ki o má si le yà ẹnu rẹ mọ nitori
itiju rẹ, nigbati inu mi ba tutù si ọ, nitori
ohun ti iwọ ti ṣe, ni Oluwa Ọlọrun wi.

## ORI 17.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, pa aló kan, si pa owe
kan fun ile Israeli;
3 Si wipe, Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; Idì
nla kan, pẹlu apá nla, alapá gigùn, o kún
fun iyẹ́; ti o ni àwọ alaràbarà, wá si Leba-
noni, o si mu ẹka igi Kedari ti o ga julọ.
4 O ke ori ọ̀munú ẹka rẹ̀ kuro, o si mu u
lọ si ilẹ òwo kan; o gbe e kalẹ ni ilu awọn
oniṣòwo.
5 O mu ninu irugbìn ilẹ na pẹlu, o si
gbìn i sinu oko daradara kan; o fi si ibi
omi nla, o si gbe e kalẹ bi igi willo.
6 O si dagba, o si di igi àjara ti o bò ti o
kuru, ẹka ẹniti o tẹ̀ sọdọ rẹ̀, gbòngbo rẹ̀ si
wà labẹ rẹ̀; bẽni o di ajara, o si pa ẹka,
o si yọ ọ̀munú jade.
7 Idì nla miran si wà pẹlu apá nla ati
iyẹ́ pupọ: si kiye si i, àjara yi tẹ̀ gbòngbo
rẹ̀ sọdọ rẹ̀, o si yọ ẹka rẹ̀ sọdọ rẹ̀, ki o le
ma b'omi si i ninu aporo ọgbà rẹ̀.
8 Ilẹ rere lẹba omi nla ni a gbìn i si, ki
o le bà yọ ẹka jade, ki o si le so eso, ki o le
jẹ́ àjara rere.
9 Wipe, Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; yio
ha gbà? on kì yio hú gbòngbo rẹ̀, kì yio si



Digitized by Google

ka eso rẹ̀ kuro, ki o le rọ? yio rọ ninu
gbogbo ewe rirú rẹ̀, ani laisi agbara nla
tabi enia pupọ̀ lati fà a tu pẹlu gbòngbo rẹ̀.
10 Nitõtọ, kiye si i, bi a ti gbìn i yi,
yio ha gbà? kì yio ha rẹ̀ patapata? nigbati
afẹfẹ ilà-õrun ba kàn a? yio rẹ̀ ninu aporo
ti o ti hù.
11 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
12 Sọ nisisiyi fun ọlọ̀tẹ ile na pe, Ẹnyin
kò mọ̀ ohun ti nkan wọnyi jasi? Sọ fun
wọn, kiyesi i, ọba Babiloni de Jerusalemu,
o si ti mu ọba ibẹ ati awọn ọmọ-alade ibẹ,
o si mu wọn pẹlu rẹ̀ lọ si Babiloni:
13 O si ti mu ninu iru-ọmọ ọba, o si bá a
dá majẹmu, o si ti mu u bura: o si mu
awọn alagbara ilẹ na pẹlu:
14 Ki ijọba na le jẹ alailọla, ki o má le
gbe ara rẹ̀ soke, ki o le duro nipa pipa
majẹmu rẹ̀ mọ.
15 Ṣugbọn on ṣọ̀tẹ si i ni rirán awọn ikọ̀
rẹ̀ lọ si Egipti, ki nwọn ki o le fi ẹṣin fun u
ati enia pupọ. Yio ha sàn a? ẹniti nṣe iru
nkan wọnyi yio ha bọ́? tabi yio dalẹ tan
ki o si bọ́?
16 Oluwa Ọlọrun wipe, Bi mo ti wà,
nitotọ ibi ti ọba ngbe ti o fi i jọba, ibura
ẹniti o gàn, majẹmu ẹniti o si bajẹ, ani lọdọ
rẹ̀ lãrin Babiloni ni yio kú.
17 Bẹ̃ni Farao ti on ti ogun rẹ̀ ti o li
agbara ati ẹgbẹ́ nla kì yio ṣe fun u ninu
ogun, nipa mimọ odi, ati kikọle iṣọ́ ti o li
agbara, lati ke enia pupọ̀ kuro:
18 Nitoriti o gàn ibura nipa didalẹ, kiye
si i, o ti fi ọwọ́ rẹ̀ fun ni, o si ti ṣe gbogbo
nkan wọnyi, kì yio bọ́.
19 Nitorina bayi ni Oluwa Ọlọrun wi;
Bi mo ti wà, dajudaju ibura mi ti o ti gàn,
ati majẹmu mi ti o ti dà, ani on li emi o
san si ori on tikalarẹ̀.
20 Emi o si nà àwọn mi si i lori, a o si
mu u ninu ẹgẹ́ mi; emi o si mu u de Ba-
biloni, emi o si ba a rojọ nibẹ, nitori ẹ̀ṣẹ ti
o ti da si mi.
21 Ati gbogbo awọn isánsa rẹ̀ pẹlu gbo-
gbo awọn ẹgbẹ́-ogun rẹ̀, ni yio ti oju idà
ṣubu; awọn ti o si kù ni a o tuka si gbogbo
ẹfũfu: ẹnyin o si mọ̀ pe emi Oluwa li o ti
sọ ọ.
22 Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; emi o mu
ninu ẹka ti o ga jùlọ, ninu igi Kedari giga;
emi o si lọ́ ọ, emi o ke ọ̀munú ẹka kan
kuro ninu ọ̀munú ẹka rẹ̀; emi o si gbìn i
sori oke giga kan ti o si hàn:
23 Lori oke giga ti Israeli ni emi o gbìn
i si, yio si yọ ẹka; yio si so eso, yio si jẹ
igi Kedari daradara; labẹ rẹ̀ ni gbogbo
ẹiyẹ oniruru iyẹ́ o si gbe; ninu ojiji ẹka rẹ̀
ni nwọn o gbe.
24 Gbogbo igi inu igbẹ ni yio si mọ̀ pe,
emi Oluwa li o ti mu igi giga walẹ, ti mo ti
gbe igi rirẹlẹ soke, ti mo ti mu igi tutù gbẹ,
ti mo si ti mu igi gbigbẹ ruwé: emi Oluwa
li o ti sọ ti mo si ti ṣe e.

## ORI 18.

Ọ̀RỌ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
2 Kini ẹnyin rò ti ẹnyin fi npowe yi
niti ilẹ Israeli, pe, Awọn baba ti jẹ eso
àjara kíkan, ehin awọn ọmọ si kan.
3 Oluwa Ọlọrun wipe, bi mo ti wà, ẹnyin
kì yio ri àye lati powe yi mọ ni ilẹ Israeli.
4 Kiye si i, gbogbo ọkàn ni t'emi; gẹgẹ
bi ọkàn baba ti jẹ t'emi, bẹ̃ni t'emi ni
ọkàn ọmọ pẹlu; ọkàn ti o bá ṣẹ̀, on o kú.
5 Ṣugbọn bi enia kan ba ṣe olõtọ, ti o si
ṣe eyiti o tọ ati eyiti o yẹ,
6 Ti kò si jẹun lori oke, ti kò si gbe oju
rẹ̀ soke si awọn oriṣa ile Israeli, ti kò si bà
obirin aladugbo rẹ̀ jẹ, ti kò sì sunmọ
obirin ti o wà ninu aimọ́ rẹ̀.
7 Ti kò si ni ẹnikan lara, ṣugbọn ti o ti
fi ohun ògo onigbèse fun u, ti kò fi agbara
kó ẹnikẹni, ti o ti fi onjẹ rẹ̀ fun ẹniti ebi
npa, ti o si ti fi ẹwu bo ẹni-ihoho.
8 Ẹniti kò fi fun ni lati gba ẹdá, bẹ̃ni
kò gba elékele, ti o ti fa ọ̀wọ́ rẹ̀ kuro ninu
aiṣedẽde, ti o ti mu idajọ otitọ ṣẹ lãrin
ọkọnrin ati ọkọnrin,
9 Ti o ti rìn ninu aṣẹ mi, ti o si ti pa
idajọ mi mọ, lati hùwa titọ́; on ṣe olõtọ,
yiyè ni yio yè, ni Oluwa Ọlọrun wi.
10 Bi o ba bi ọmọkọnrin kan ti iṣe ọlọṣà,
oluta ẹ̀jẹ silẹ, ti o si nṣe ohun ti o jọ ọkan
ninu nkan wọnyi si arakọnrin rẹ̀.
11 Ti kò si ṣe ọkan ninu gbogbo iṣẹ
wọnni, ṣugbọn ti o tilẹ ti jẹun lori oke, ti o
si ba obirin aladugbo rẹ̀ jẹ,
12 Ti o ti ni talaka ati alaini lara; ti o
ti fi agbara koni, ti kò mu ohun ògo pada,
ti o ti gbe oju rẹ̀ soke si oriṣa, ti o ti ṣe
ohun irira,
13 Ti o ti fi fun ni lati gba ẹdá, ti o si ti
gba èle: on o ha yè bẹ̃? on kì yio yè: on
ti ṣe gbogbo ohun irira wọnyi; kikú ni yio
kú: ẹjẹ rẹ yio wà lori rẹ̀.
14 Si kiye si i, bi o ba bi ọmọkọnrin ti o
ri gbogbo ẹ̀ṣẹ baba rẹ̀ ti o ti ṣe, ti o si bẹru,
ti kò si ṣe iru rẹ̀,
15 Ti kò si jẹun lori oke, ti kò gbe oju
rẹ̀ soke si oriṣa ile Israeli, ti kò ba obirin
aladugbo rẹ̀ jẹ,
16 Ti kò ni ẹnikan lara, ti kò dá ohun

Digitized by Google

ògo duro, ti kò fi agbara koni, ṣugbọn ti o
ti fi onjẹ rẹ̀ fun ẹniti ebi npa, ti o si ti fi
ẹ̀wu bo ẹni-ihoho,
17 Ti o ti mu ọwọ́ rẹ̀ kuro lara ẹni-inila-
ra, ti kò ti gba ẹdá tabi elé, ti o ti mu idajọ
mi ṣẹ, ti o ti rìn ninu aṣẹ mi; on kì yio kú
nitori aiṣedẽde baba rẹ̀, yiyè ni yio yè.
18 Bi o ṣe ti baba rẹ̀, nitoripe o fi ikà
ninilara, ti o fi agbara ko arakọnrin rẹ̀; ti
o ṣẹ eyiti kò dara lãrin enia rẹ̀, kiye si i, on
o tilẹ kú ninu aiṣedẽde rẹ̀.
19 Ṣugbọn ẹnyin wipe, Ẽṣe? ọmọ kò ha
ru aiṣedẽde baba? Nigbati ọmọ ti ṣe eyiti
o tọ́ ati eyiti o yẹ, ti o si ti pa gbogbo aṣẹ
mi mọ, ti o si ti ṣe wọn, yiyè ni yio yè.
20 Ọkàn ti o ba ṣẹ̀, on o kú. Ọmọ kì
yio rù aiṣedẽde baba, bẹ̃ni baba kì yio rù
aiṣedẽde ọmọ: ododo olododo yio wà lori
rẹ̀, ìwa buburu enia buburu yio si wà lori
rẹ̀.
21 Ṣugbọn bi enia buburu yio ba yipada
kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ti da, ti o si
pa gbogbo aṣẹ mi mọ, ti o si ṣe eyi ti o tọ́,
ati eyiti o yẹ, yiyè ni yio yè, on kì yio kú.
22 Gbogbo irekọja rẹ̀ ti o ti ṣe, a kì yio
ranti wọn si i: ninu ododo rẹ̀ ti o ti ṣe ni
on o yè.
23 Emi ha ni inu-didùn rara pe ki enia
buburu ki o kú? ni Oluwa Ọlọrun wi: kò
ṣepe ki o yipada kuro ninu ọ̀na rẹ̀, ki o si
yè?
24 Ṣugbọn nigbati olododo ba yipada
kuro ninu ododo rẹ̀, ti o si huwà aiṣedede,
ti o si ṣe gẹgẹ bi gbogbo irira ti enia buburu
nṣe, on o ha yè? gbogbo ododo rẹ̀ ti o ti ṣe
ni a kì yio ranti: ninu irekọja rẹ̀ ti o ti ṣe,
ati ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o ti da, ninu wọn ni yio
kú.
25 Ṣugbọn ẹnyin wipe, ọ̀na Oluwa kò
gún. Gbọ́ nisisiyi, iwọ ile Israeli; ọ̀na mi
kò ha gún? ọ̀na ti nyin kọ́ kò gùn?
26 Nigbati olododo kan ba yipada kuro
ninu ododo rẹ̀, ti o si huwà aiṣedẽde, ti o
si kú ninu wọn; nitori aiṣedẽde rẹ̀ ti o ti
ṣe ni yio kú.
27 Ẹwẹ, nigbati enia buburu ba yipada
kuro ninu ìwa buburu rẹ̀ ti o ti ṣe, ti o si
ṣe eyiti o tọ́, ati eyiti o yẹ, on o gba ọkàn
rẹ̀ là lãye.
28 Nitoripe o bẹ̀ru o si yipada kuro ninu
gbogbo irekọja rẹ̀ ti o ti ṣe, yiyè ni yio yè,
on kì yio kú.
29 Ṣugbọn ile Israeli wipe, Ọ̀na Oluwa kò
gún. Ile Israeli, ọ̀na mi kò ha gún? ọ̀na
ti nyin kọ́ kò gún?
30 Nitorina emi o dá nyin lẹjọ, ile Isra-
eli, olukuluku gẹgẹ bi ọ̀na rẹ̀, ni Oluwa
Ọlọrun wi. Ẹ yipada, ki ẹ si yi kuro ninu
gbogbo irekọja nyin; bẹ̃ni aiṣedẽde kì yio
jẹ iparun nyin.
31 Ẹ ta gbogbo irekọja nyin nù kúro
lọdọ nyin, nipa eyiti ẹnyin fi rekọja; ẹ si
dá ọkàn titun ati ẹmi titun fun ara nyin:
nitori kini ẹnyin o ṣe kú, ile Israeli?
32 Nitoripe emi kò ni inu didùn si ikú
ẹniti o kú, ni Oluwa Ọlọrun wi: nitorina ẹ
yi ara nyin pada, ki ẹ si yè.

## ORI 19.

PẸLUPẸLU iwọ pohùn-rére ẹkun fun
awọn ọmọ-alade Israeli,
2 Si wipe, Kini iyá rẹ? Abo kiniun: o
dubulẹ lãrin kiniun, o bọ́ awọn ọmọ rẹ lãrin
ọmọ kiniun.
3 O si tọ́ ọkan ninu ọmọ rẹ̀ dàgba: o di
ọmọ kiniun, o si kọ́ ati ṣọdẹ; o pa enia jẹ.
4 Awọn orilẹ-ède pẹlu gburo rẹ̀: a mu u
ninu iho wọn, nwọn si fi ẹ̀wọn mu u lọ si
ilẹ Egipti.
5 Nigbati o si ri pe on si duro, ti ireti rẹ̀
si sọnu, nigbana ni o mu omiran ninu ọmọ
rẹ̀, o si sọ ọ di ọmọ kiniun.
6 On si lọ soke lọ sodo lãrin awọn kiniun,
o di ọmọ kiniun, o si kọ́ lati ṣọdẹ, o si pa
enia jẹ.
7 On si mọ̀ awọn opo wọn, o si sọ ilu-nla
wọn di ahoro; ilẹ na di ahoro, ati ẹkún rẹ̀,
pẹlu nipa ariwo kike ramuramu rẹ̀.
8 Nigbana ni awọn orilẹ-ède kó tì i nihà
gbogbo lati ìgberiko wá, nwọn si na awọ̀n
wọn le e lori: a mu u ninu iho wọn.
9 Nwọn si fi i sinu ẹṣọ́ ninu ẹ̀wọn, nwọn
si mu u wá sọdọ ọba Babiloni: nwọn mu
u lọ sinu ilu olodi, ki a má ba gbọ́ ohùn rẹ̀
mọ lori oke Israeli.
10 Iyá rẹ dabi àjara kan ninu ẹjẹ rẹ, ti
a gbìn si eti odò, on kún fun eso, o si kún
fun ẹka nitori ọ̀pọlọpọ odò.
11 O si ni ọpá ti o le fun ọpá-ade awọn
ti o jẹ oye; giga rẹ̀ li a gbega lãrin ẹka
gigun, o si farahàn ninu giga rẹ̀ pẹlu ọ̀pọ-
lọpọ ẹka rẹ̀.
12 Ṣugbọn a fà a tu ni irúnu, a wọ ọ lulẹ,
ẹfũfu ila-õrun si gbẹ eso rẹ̀, ọpá lile rẹ̀ ti ṣẹ,
o si rọ; iná jo o run.
13 Nisisiyi a si gbìn i si aginju, ni ilẹ
gbigbẹ ati ilẹ ongbẹ.
14 Iná si jade lati inu ọpá kan ninu ẹka
rẹ̀, ti o ti jo eso rẹ̀ run, tobẹ̃ ti kò fi ni ẹka
ti o le lati ṣe ọpa lati joye. Eyi ni ohùn-
réré ẹkun, yio si jẹ ohùnréré ẹkun.

Digitized by Google

## ORI 20.

OSI ṣe ni ọdun keje ni oṣu karun, ni ọjọ kẹwa oṣu, ti awọn kan ninu awọn àgba Israeli wá ibere lọwọ Oluwa, nwọn si joko niwaju mi.

2 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá, wipe,

3 Ọmọ enia, sọ fun awọn àgba Israeli, si wi fun wọn pe, Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi: Lati bere lọwọ mi ni ẹ ṣe wá? Oluwa Ọlọrun wipe, Bi mo ti wà, lọwọ mi kọ́ ẹnyin o bere.

4 Iwọ o ha dá wọn lẹjọ bi, ọmọ enia, iwọ o ha da wọn lẹjọ? jẹ ki wọn mọ̀ ohun-irira baba wọn.

5 Si wi fun wọn pe, Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; Ni ọjọ na nigbati mo yàn Israeli, ti mo si gbe ọwọ́ mi soke si iru-ọmọ ile Jakobu, ti mo si sọ ara mi di mimọ̀ fun wọn ni ilẹ Egipti, nigbati mo gbe ọwọ́ mi soke si wọn, wipe, Emi ni Oluwa Ọlọrun nyin:

6 Ni ọjọ ti mo gbe ọwọ́ mi soke si wọn, lati mu wọn jade lati ilẹ Egipti si ilẹ ti mo ti wò silẹ fun wọn, ti nṣàn fun wàra ati fun oyin, ti iṣe ogo gbogbo ilẹ.

7 Mo si wi fun wọn pe, Ki olukuluku ninu nyin gbe irira oju rẹ̀ junù, ẹ má si ṣe fi oriṣa Egipti sọ ara nyin di aimọ́; emi ni Oluwa Ọlọrun nyin.

8 Ṣugbọn nwọn ṣọ̀tẹ si mi, nwọn kò si fẹ fi eti si mi: olukuluku wọn kò gbe ohun-irira oju wọn junù, bẽni nwọn kò kọ oriṣa Egipti silẹ: nigbana ni mo wipe, emi o da irúnu mi si wọn lori, lati pari ibinu mi si wọn lãrin ilẹ Egipti.

9 Ṣugbọn mo ṣiṣẹ nitori orukọ mi; ki o má bà bajẹ niwaju awọn keferi, lãrin ẹniti nwọn wà, loju ẹniti mo sọ ara mi di mimọ̀ fun wọn, ni mimu wọn jade kuro ni ilẹ Egipti.

10 Mo si jẹ ki nwọn lọ kuro ni ilẹ Egipti, mo si mu wọn wá si aginju.

11 Mo si fi aṣẹ mi fun wọn, mo si fi idajọ mi hàn wọn, eyiti bi enia kan ba ṣe, yio tilẹ yè ninu wọn.

12 Pẹlupẹlu mo si fun wọn ni ọjọ isimi mi, lati ṣe àmi lãrin t'emi ti wọn, ki nwọn ki o le mọ̀ pe emi ni Oluwa ti o yà wọn si mimọ́.

13 Ṣugbọn ile Israeli ṣọ̀tẹ si mi ni aginjù: nwọn kò rìn ni aṣẹ mi, nwọn si gàn idajọ mi, eyiti bi enia kan ba ṣe, on o tilẹ yè ninu wọn; ati ọjọ isimi mi ni wọn tilẹ bajẹ gidigidi: nigbana ni mo wipe, emi o dà irúnu mi si wọn lori li aginju, lati pa wọn run.

14 Ṣugbọn mo ṣiṣẹ nitori orukọ mi, ki o má ba di ibajẹ niwaju awọn keferi, loju ẹniti mo mu wọn jade.

15 Pẹlupẹlu mo gbe ọwọ́ mi soke si wọn ni aginju pe emi kò ni mu wọn de ilẹ ti mo ti fi fun wọn, ti nṣàn fun wàra ati fun oyin, ti iṣe ogo gbogbo ilẹ;

16 Nitoriti nwọn gàn idajọ mi, nwọn kò si rìn ninu aṣẹ mi, ṣugbọn nwọn bà ọjọ isimi mi jẹ: nitoripe ọkàn wọn tẹ̀le oriṣa wọn.

17 Ṣugbọn oju mi dá wọn si ki emi má ba pa wọn, bẽni emi kò ṣe wọn li aṣetan ni aginju.

18 Ṣugbọn mo sọ fun awọn ọmọ won li aginju pe, Ẹ máṣe rìn ninu aṣẹ baba nyin, ẹ má si ṣe kiyesi idajọ wọn, ẹ má si fi oriṣa wọn sọ ara nyin di aimọ́:

19 Emi ni Oluwa Ọlọrun nyin: ẹ rìn ninu aṣẹ mi, ẹ si pa idajọ mi mọ, ẹ si ṣe wọn;

20 Ẹ si bọ̀wọ fun ọjọ isimi mi; nwọn o si jẹ àmi lãrin t'emi ti nyin, ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe emi ni Oluwa Ọlọrun nyin.

21 Ṣugbọn awọn ọmọ na ṣọ̀tẹ si mi: nwọn kò rìn ninu aṣẹ mi, bẽni nwọn kò pa idajọ mi mọ lati ṣe wọn, eyiti bi enia kan ba ṣe, yio tilẹ yè ninu wọn; nwọn bà ọjọ isimi mi jẹ: mo si wipe, Emi o da irúnu mi sori wọn, lati pari ibinu mi sori wọn li aginju.

22 Ṣugbọn mo fà ọwọ́ mi sẹhìn, mo si ṣiṣẹ nitori orukọ mi, ki o má bà di ibajẹ li oju awọn keferi, loju ẹniti mo mu wọn jade.

23 Mo gbe ọwọ́ mi soke si wọn pẹlu li aginju, lati tú wọn ka lãrin awọn keferi, ati lati fọ́n wọn ká ilẹ gbogbo;

24 Nitoripe nwọn kò mu idajọ mi ṣẹ, ṣugbọn nwọn kẹgàn aṣẹ mi, nwọn si ti bà ọjọ isimi mi jẹ, oju wọn si wà lara oriṣa baba wọn.

25 Nitorina mo fun wọn ni aṣẹ pẹlu ti kò dara, ati idajọ nipa eyiti wọn kì yio fi le yè;

26 Emi si bà wọn jẹ́ ninu ẹ̀bun ara wọn, nitipe nwọn mu gbogbo awọn akọbi kọja lãrin iná, ki emi ba le sọ wọn di ahoro, ki nwọn le bà mọ̀ pe emi ni Oluwa.

27 Nitorina, ọmọ enia, sọ fun ile Israeli si wi fun wọn pe, Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; Ninu eyi pẹlu baba nyin ti sọ̀rọ odi si mi, nitipe nwọn ti dẹṣẹ si mi.

28 Nitori nigbati mo ti mu wọn de ilẹ, niti eyiti mo gbé ọwọ́ mi soke lati fi i fun

Digitized by Google

wọn, nigbana ni nwọn ri olukuluku oke
giga, ati gbogbo igi bibò, nwọn si ru ẹbọ
wọn nibẹ, nwọn si gbe imunibinu ọrẹ wọn
kalẹ nibẹ: nibẹ pẹlu ni nwọn ṣe õrun didùn
wọn, nwọn si ta ohun-ọrẹ mimu silẹ nibẹ.
29 Nigbana ni mo wi fun wọn pe, Kini
ibi giga ti ẹnyin nlọ na? Orukọ rẹ̀ ni a
si npe ni Bama titi o fi di oni oloni.
30 Si wi fun ile Israeli pe, Bayi ni Oluwa
Ọlọrun wi; A bà nyin jẹ́ gẹgẹ bi baba
nyin? ẹnyin si ṣe agbère gẹgẹ bi ohun-
irira wọn.
31 Nitori nigbati ẹnyin nta ọrẹ nyin,
nigbati ẹnyin mu ọmọ nyin kọja lãrin iná,
ẹnyin fi oriṣa nyin bà ara nyin jẹ́, ani titi
o fi di-oni oloni: ẹnyin o ha si bere lọwọ
mi, Iwọ ile Israeli? Bi mo ti wà, ni
Oluwa Ọlọrun wi, lọwọ mi kọ́ ẹnyin o bere.
32 Eyiti o si wá si iye nyin kì yio wà
rara; ti ẹnyin wipe, Awa o wà bi awọn
keferi, gẹgẹ bi idile awọn orilẹ-ède lati bọ
igi ati okuta.
33 Bi mo ti wà, ni Oluwa Ọlọrun wi,
nitõtọ nipa agbara ọwọ́, ati ninà apa, pẹlu
irúnu ti a dà jade li emi o fi jọba lori nyin:
34 Emi o si mu nyin jade kuro lãrin
awọn enia, emi o si ṣà nyin jọ lati ilẹ ti a
ti tú nyin ka si, pẹlu ọwọ́ agbara, ati ninà
apa, ati pẹlu irúnu ti a dà jade.
35 Emi o si mu nyin wá si aginju awọn
enia, nibẹ ni emi o si bá nyin rojọ lojukoju.
36 Gẹgẹ bi mo ti dá awọn baba nyin lẹjọ
li aginju ilẹ Egipti, bẹ̃ni emi o bá nyin
rojọ, ni Oluwa Ọlọrun wi.
37 Emi o si mu nyin kọja labẹ ọpá, emi
o si mu nyin wá si ìde majẹmu:
38 Emi o si ṣà awọn ọlọ̀tẹ kuro lãrin
nyin, ati awọn olurekọja, emi o mu wọn
jade kuro ni ilẹ ti wọn gbe ṣe atipo, nwọn
kì yio si wọ ilẹ Israeli: ẹnyin o si mọ̀ pe
emi ni Oluwa.
39 Bi o ṣe ti nyin, ile Israeli, Bayi ni
Oluwa Ọlọrun wi, Ẹ lọ, olukuluku sìn oriṣa
rẹ̀, ati lẹhin eyi pẹlu, bi ẹnyin kì yio ba fi
eti si mi: ṣugbọn ẹ máṣe fi ẹ̀bun nyin ati
oriṣa nyin bà orukọ mimọ́ mi jẹ́ mọ.
40 Nitori lori oke mimọ́ mi, lori oke
giga Israeli, ni Oluwa Ọlọrun wi, nibẹ ni
gbogbo ile Israeli, gbogbo wọn ni ilẹ na,
yio sìn mi: nibẹ ni emi o gbà wọn, nibẹ
ni emi o si bere ẹbọ nyin, ati ọrẹ akọso
nyin, pẹlu ohun mimọ́ nyin.
41 Emi o gbà nyin pẹlu õrùn didún
nyin, nigbati mo mu nyin jade kuro lãrin
awọn enia, ti mo si ko nyin jọ lati ilẹ
gbogbo nibiti a gbe ti tú nyin ká si; a o
si yà mi si mimọ́ ninu nyin niwaju awọn
keferi.
42 Ẹnyin o si mọ̀ pe emi ni Oluwa,
nigbati emi o mu nyin de ilẹ Israeli, si
ilẹ niti eyiti mo gbe ọwọ́ mi soke lati fi
fun awọn baba nyin.
43 Nibẹ li ẹnyin o ranti ọ̀na nyin, ati
gbogbo iṣe nyin ninu eyiti a ti bà nyin
jẹ; ẹ o si sú ara nyin loju ara nyin nitori
gbogbo buburu ti ẹnyin ti ṣe.
44 Ẹnyin o si mọ̀ pe emi ni Oluwa,
nigbati emi ti ṣiṣẹ pẹlu nyin nitori orukọ
mi, ki iṣe gẹgẹ bi ọ̀na buburu nyin, tabi
gẹgẹ bi iṣe bibajẹ nyin, ẹnyin ile Israeli,
ni Oluwa Ọlọrun wi.
45 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
46 Ọmọ enia, kọju rẹ siha gusù, si sọ
ọ̀rọ rẹ siha gusù, si sọtẹlẹ si igbó oko gusù;
47 Si wi fun igbó gusù pe, Gbọ́ ọ̀rọ
Oluwa; bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; Kiyesi
i, emi o da iná kan ninu rẹ, yio si jo olu-
kuluku igi tutù ninu rẹ, ati olukuluku igi
gbigbẹ: jijo ọwọ́ iná na ni a kì yio pa, ati
gbogbo oju lati gusu de ariwa ni a o sun
ninu rẹ̀.
48 Gbogbo ẹran-ara ni yio si ri i pe emi
Oluwa li o ti da a, a kì yio pa a.
49 Nigbana ni mo wipe, A! Oluwa
Ọlọrun, nwọn wi niti emi pe, Owe ki o
npa yi?

## ORI 21.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe.
2 Ọmọ enia, kọju rẹ sihà Jerusalemu,
si sọ ọ̀rọ si ibi mimọ́ wọnni, si sọtẹlẹ si ilẹ
Israeli.
3 Si wi fun ilẹ Israeli pe, Bayi li Oluwa
Ọlọrun wi; Kiyesi i, mo dojukọ ọ, emi o
si fa idà mi yọ kuro li akọ̀ rẹ̀, emi o si ke
olododo ati enia buburu kuro lãrin rẹ.
4 Njẹ bi o ti ṣe pe emi o ke olododo ati
enia buburu kuro lãrin rẹ, nitorina ni idà
mi o ṣe jade lọ lati inu àkọ rẹ̀, si gbogbo
ẹran-ara, lati gusù de ariwa:
5 Ki gbogbo ẹran-ara le mọ̀ pe emi
Oluwa ti fà idà mi yọ kuro li àkọ rẹ̀: kì
yio pada mọ lai.
6 Nitorina kerora, iwọ ọmọ enia, pẹlu
ṣiṣẹ́ ẹgbẹ́ rẹ, ati pẹlu ikerora kikoro niwaju
wọn.
7 Yio si ṣe, nigbati nwọn ba wi fun ọ
pe, Ẽṣe ti iwọ fi nkerora? iwọ o dahùn
wipe, Nitori ihìn na; nitoripe o de: olu-
kuluku ọkàn ni yio yọ́, gbogbo ọwọ́ ni yio
si ṣe ainokun, olukuluku ẹmi yio si dakú,
gbogbo ẽkún ni yio ṣe ailagbara bi omi:

Digitized by Google

kiyesi i, o de, a o si mu u ṣẹ, ni Oluwa
Ọlọrun wi.
8 Ọrọ Oluwa si tun tọ̀ mi wá, wipe,
9 Ọmọ enia, sọtẹlẹ, si wipe, Bayi li
Oluwa wi; Wipe, Idà, idà ti a pọ́n, ti a si
dán pẹlu:
10 A pọ́n ọ lati pa enia pupọ; a dán a
lati ma kọ màna: awa o ha ma ṣe ariyá?
ọgọ ọmọ mi, o gàn gbogbo igi.
11 On si ti fi i le ni lọwọ lati dán, ki
a ba le lò o; idà yi li a pọ́n, ti a si dán,
lati fi i le ọwọ́ apani.
12 Kigbe, ki o si wu, ọmọ enia: nitori
yio wá sori awọn enia mi, yio wá sori gbo-
gbo ọmọ-alade Israeli: ìbẹru nla yio wá
sori awọn enia mi nitori idà na: nitorina
lu itan rẹ.
13 Nitoripe idanwo ni, ki si ni bi idà
na gàn ọgọ na? ki yio si mọ́, ni Oluwa
Ọlọrun wi.
14 Nitorina, iwọ ọmọ enia, sọtẹlẹ, si fi
ọwọ́ lu ọwọ́ pọ̀, si jẹ ki idà ki o ṣẹ̀po nigba
kẹta, idà awọn ti a pa: idà awọn enia nla
ti a pa ni, ti o wọ inu yara ikọ̀kọ wọn lọ.
15 Mo ti nà ṣonṣo idà si gbogbo bode
wọn: ki aiya wọn le dakú, ati ki ahoro
wọn le di pupọ: ã! a ti ṣe e dán, a ti pọ́n
ọ mú silẹ fun pipa.
16 Iwọ gba ọ̀na kan tabi ọ̀na keji lọ, si
apa ọtún tabi si òsi, nibikibi ti iwọ dojukọ.
17 Emi o si fi ọwọ́ lu ọwọ́ pọ̀, emi o si
jẹ ki irúnu mi ki o simi: emi Oluwa li o
ti wi bẽ.
18 Ọrọ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
19 Iwọ, pẹlu, ọmọ enia, yan ọ̀na meji
fun ara rẹ, ki idà ọba Babiloni ki o le wá:
awọn mejeji yio jade lati ilẹ kanna wá: si
yan ibi kan, yàn a ni ikorita ti o lọ si ilu-
nla.
20 Yàn ọ̀na kan, ki idà na le wá si
Rabba ti awọn ara Ammoni, ati si Juda ni
Jerusalemu ti o li odi.
21 Nitori ọba Babiloni duro ni iyàna,
lori ọ̀na meji, lati ma lo afọṣẹ: o mì ọfà
rẹ̀, o da òriṣa, o wo ẹ̀dọ.
22 Li ọwọ́ ọtún rẹ̀ ni afọṣẹ Jerusalemu
wà, lati yan õlù, lati ya ẹnu rẹ̀ ni pipa,
lati gbohùn soke pẹlu ariwo, lati yan õlù
si bode, lati mọ odi, ati lati kọ ile iṣọ́.
23 Afọ̀ṣẹ na yio si dabi eké fun wọn,
loju awọn ti o ti bura fun wọn: ṣugbọn
on o mu aiṣedẽde wá si iranti, ki a ba le
mu wọn.
24 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Nitoripe ẹnyin jẹ ki a ranti aiṣedẽde nyin,
niti pe a ri irekọja nyin, tobẽ ti ẹ̀ṣẹ nyin
hàn, ni gbogbo iṣe nyin: nitoripe ẹnyin
wá si iranti, ọwọ́ li a o fi mu nyin.
25 Ati iwọ, alailọ̀wọ ẹni-buburu ọmọ-
alade Israeli, ẹniti ọjọ rẹ̀ de, nigba aiṣedẽde
ikẹhìn.
26 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Mu fila
ọba kuro, si ṣi ade kuro; eyi kò ni jẹ
ọkanna: gbe ẹniti o rẹlẹ ga, si rẹ̀ ẹniti o
ga silẹ.
27 Emi o bì ṣubu, emi o bì ṣubu, emi o
bì i subu, ki yio si si mọ, titi igbati ẹniti
o ni i ba de; emi o si fi fun u.
28 Ati iwọ, ọmọ enia, sọtẹlẹ, si wipe,
Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi niti awọn ara
Ammoni, ati niti ẹgàn wọn; ani ki iwọ
wipe, Idà na, idà na ti a fà yọ, a ti dàn a
fun pipa, lati parun lati kọ màna.
29 Nigbati nwọn ri ohun asan si ọ, ni-
gbati nwọn fọ̀ àfọṣẹ eke si ọ, lati mu ọ wá
si ọrùn awọn ti a pa, ti ẹni-buburu, ẹniti
ọjọ rẹ̀ de, nigbati aiṣedẽde pin.
30 Tun mu ki o pada sinu àkọ rẹ̀! Emi
o ṣe idajọ rẹ nibi ti a gbe ṣe ẹdá rẹ, ni ilẹ ibi
rẹ.
31 Emi o dà ibinujẹ mi le ọ lori, ninu
iná irúnu mi li emi o fẹ si ọ, emi o si fi ọ
le awọn eniakenia lọwọ, ti nwọn ni ọgbọn
lati parun.
32 Iwọ o jẹ́ igi fun iná; ẹjẹ rẹ yio wà
lãrin ilẹ na; a ki yio ranti rẹ mọ: nitori
emi Oluwa li o ti wi i.

## ORI 22.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
2 Njẹ, iwọ ọmọ enia, iwọ o ha ṣe
idajọ, iwọ o ha ṣe idajọ ilu ẹlẹjẹ na? nitõ-
tọ, iwọ o jẹ ki o mọ̀ ohun irira rẹ̀ gbogbo.
3 Nitorina, iwọ wipe, Bayi li Oluwa
Ọlọrun wi, Ilu ti o ta ẹjẹ silẹ lãrin rẹ̀, ki
akoko rẹ̀ ki o le de, o si ṣe oriṣa si ara rẹ̀
lati sọ ara rẹ̀ di aimọ́.
4 Iwọ ti di ẹlẹbi niti ẹjẹ rẹ ti iwọ ti ta
silẹ; iwọ si ti sọ ara rẹ di aimọ́ niti òriṣa
rẹ ti iwọ ti ṣe, iwọ si ti mu ọjọ rẹ summọ
tosí, iwọ si ti dé ọdun rẹ: nitorina ni mo
ṣe sọ ọ di ẹgàn si awọn keferi, ati ẹsín si
gbogbo ilẹ.
5 Awọn ti o sunmọ tosí, ati awọn ti o
jìna si ọ, yio fi ọ ṣẹ̀sin, iwọ ti a bà orukọ
rẹ̀ jẹ, ti a si bà ninu jẹ pupọ.
6 Kiyesi i, awọn ọmọ-alade Israeli, olu-
kuluku ninu agbara rẹ̀ wà ninu rẹ lati ta
ẹjẹ silẹ.
7 Ninu rẹ ni nwọn kò ka baba ati iyá
si: lãrin rẹ ni nwọn ti ni awọn alejo lara:

Digitized by Google

ninu rẹ ni nwọn ti bà alaini-baba ati opo
ninu jẹ.
8 Iwọ ti gan awọn ohun mimọ́ mi, o si
ti sọ ọjọ isimi mi di ailọ̀wọ.
9 Ninu rẹ ni awọn ọkọnrin ti o nṣe ofófo
lati ta ẹjẹ silẹ wà: ninu rẹ ni nwọn si jẹun
lori awọn oke: lãrin rẹ ni nwọn huwà
ifẹkufẹ.
10 Ninu rẹ ni nwọn ti tu ihòho baba
wọn: ninu rẹ ni nwọn ti tẹ́ obirin ti a yà
sapakan nitori aimọ́ rẹ̀ logo.
11 Ẹnikan si ti ṣe ohun irira pẹlu aya
aladugbo rẹ̀: ẹlomiran si ti fi ifẹkufẹ bà
aya-ọmọ rẹ̀ jẹ́; ẹlomiran ninu rẹ si ti tẹ́
arabirin rẹ̀ logo, ọmọ baba rẹ̀.
12 Ninu rẹ ni nwọn ti gba ẹbùn lati ta
ẹjẹ silẹ: iwọ ti gba ẹdá ati elé, o si ti fi
iwọra jère lara awọn aladugbo rẹ, nipa ifi
ilọni lọwọ-gbà; o si ti gbagbe mi, ni Oluwa
Ọlọrun wi.
13 Kiyesi i, nitorina, mo ti fi ọwọ́ lu ọwọ̀
pọ̀ si ère aiṣõtọ rẹ ti o ti jẹ, ati si ẹjẹ rẹ ti
o ti wà lãrin rẹ.
14 Ọkàn rẹ le gbà a, tabi ọwọ́ rẹ lè le, li
ọjọ ti emi o ba ọ ṣe? emi Oluwa li o ti sọ
ọ, emi o si ṣe e.
15 Emi o fọ́n ọ ká sãrin awọn keferi,
emi o si tú ọ ká si orilẹ-ède gbogbo, emi o
si run ẽri rẹ kuro lara rẹ.
16 A o si sọ ọ di aìlọwọ ninu ara rẹ
loju awọn keferi, iwọ o si mọ̀ pe emi li
Oluwa.
17 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
18 Ọmọ enia, ile Israeli di idarọ si mi:
gbogbo wọn jẹ idẹ, ati tánganran, ati irin,
ati ojé, lãrin ileru; ani nwọn jẹ idarọ
fadaka.
19 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Nitori ti gbogbo nyin di idarọ, kiyesi i,
nitorina emi o ko nyin jọ si ãrin Jeru-
salemu.
20 Gẹgẹ bi nwọn ti ima ko fadaka, ati
idẹ, ati irin, ati ojé, ati tánganran jọ si
ãrin ileru, lati fin iná si i, ki a lè yọ́ ọ,
bẹ̃ni emi o kó nyin ni ibinu mi, ati irúnu
mi, emi o si fi nyin sibẹ emi o yọ́ nyin.
21 Nitotọ, emi o ko nyin jọ, emi o si fin
iná ibinu mi si nyin lara, ẹ o si di yiyọ́
lãrin rẹ̀.
22 Bi a ti iyọ́ fadaka lãrin ileru, bẹ̃li a
o yọ́ nyin lãrin rẹ̀; ẹnyin o si mọ̀ pe emi
Oluwa li o ti dà irúnu mi si nyin lori.
23 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
24 Ọmọ enia, sọ fun u, Iwọ ni ilẹ ti a
kò gbá mọ́, ti a kò si rọ̀jo si i lori lọjọ
ibinu.
25 Ìditẹ awọn wolĩ rẹ̀ wà lãrin rẹ̀, bi
kiniun ti nke ramuramu ti nṣọdẹ; nwọn
ti jẹ ọkàn run, nwọn ti kọ́ ohun iṣura ati
ohun iyebiye; nwọn ti sọ ọ̀pọlọpọ di opó
fun u lãrin rẹ̀.
26 Awọn alufa rẹ̀ ti rú ofin mi, nwọn
si ti sọ ohun mimọ́ mi di àilọwọ: nwọn kò
fi ìyatọ sãrin ohun mimọ́ ati àilọwọ, bẹ̃ni
nwọn kò fi ìyatọ hàn lãrin ohun aimọ́, ati
mimọ́, nwọn si ti fi oju wọn pamọ kuro
li ọjọ isimi mi, mo si di ẹni àilọwọ lãrin
wọn.
27 Awọn ọmọ-alade ãrin rẹ̀ dabi kõkò ti
nṣọdẹ, lati tàjẹ silẹ, lati pa ọkàn run, lati
jère aiṣõtọ.
28 Ati awọn wolĩ rẹ̀ ti fi ẹfun kùn wọn,
nwọn nri asan, nwọn si nfọ afọ̀ṣẹ eke si
wọn, wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, ni-
gbati o ṣepe Oluwa kò sọ̀rọ.
29 Awọn enia ilẹ na, ti lo ìwa-ininilara,
nwọn si ja olè, nwọn si ti bi awọn talaka
ati alaini ninu: nitõtọ, nwọn ti ni alejò
lara lainidi.
30 Emi si wá ẹnikan lãrin wọn, ti bá
tun odi na mọ, ti ibá duro ni ibiti o ya na
niwaju mi fun ilẹ na, ki emi má bà parun:
ṣugbọn emi kò ri ẹnikan.
31 Nitorina ni mo ṣe dà ibinu mi si wọn
lori; mo ti fi iná ibinu mi run won: mo si
ti fi ọ̀na wọn gbẹsan lori ara wọn, li Oluwa
Ọlọrun wi.

## ORI 23.

Ọ̀RỌ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, obirin meji wà, ọmọbirin
iyá kanna:
3 Nwọn si ṣe panṣaga ni Egipti; nwọn
ṣe panṣaga nigba ewe wọn: nibẹ ni a tẹ̀
ọmú wọn, nibẹ ni wọn si rin ọmú igbà
wundia wọn.
4 Orukọ wọn si ni Ahola, ti iṣe ẹ̀gbọn,
ati Aholiba aburo rẹ̀: ti emi si ni nwọn,
nwọn si bi ọmọkọnrin ati ọmọbirin. Orukọ
wọn ni eyi; Samaria ni Ahola, Jerusalemu
si li Aholiba.
5 Ahola si ṣe panṣaga, nigbati o jẹ ti
emi; o si fẹ awọn olufẹ rẹ̀ li afẹju, awọn
ara Assiria aladugbo rẹ̀,
6 Ti a fi aṣọ alaro bò lara, awọn balogun
ati awọn olori, gbogbo nwọn jẹ ọmọkọnrin
ti o wun ni, awọn ẹlẹṣin ti o ngùn ẹṣin.
7 Bayi li o ṣe panṣaga rẹ pẹlu wọn, pẹlu
gbogbo awọn aṣàyan ọkọnrin Assiria, ati
pẹlu gbogbo awọn ti o fẹ li afẹ̀jù: o fi
gbogbo oriṣa wọn ba ara rẹ̀ jẹ.
8 Bẹ̃ni kò fi panṣaga rẹ̀ ti o mu ti Egipti

Digitized by Google

wá silẹ: nitori nigba ewe rẹ̀ ni nwọn ba a
sùn, nwọn si rin ọmú ìgba wundia rẹ̀, nwọn
si dà panṣaga wọn si i lara.
9 Nitorina na ni mo ti fi le ọwọ́ awọn
olufẹ rẹ̀, le ọwọ́ awọn ara Assiria, awọn ti o
fẹ li afẹju.
10 Awọn wọnyi tu ìhoho rẹ̀ silẹ: nwọn
mu awọn ọmọ rẹ̀ ọkọnrin ati awọn ọmọ rẹ̀
obirin, nwọn si fi idà pa a: o si di ẹni-olo-
kiki lãrin awọn obirin; nitori pe nwọn ti
mu idajọ ṣẹ si i lara.
11 Nigbati Aholiba aburo ri eyi, o wà
bàjẹ ju on lọ ni ìwa ifẹkufẹ rẹ̀, ati ni pan-
ṣaga rẹ̀ ju ẹ̀gbọn rẹ̀ lọ ni panṣaga rẹ̀.
12 O fẹ awọn ara Assiria aludugbo rẹ̀ li
afẹju, awọn balogun ati awọn olori, ti a wọ̀
li aṣọ daradara, awọn ẹlẹṣin ti o ngùn ẹṣin,
gbogbo wọn jẹ ọmọkọnrin ti o wunni.
13 Nigbana ni mo ri pe a bà a jẹ, awọn
mejeji gba ọ̀na kan.
14 Ati pe o mu ki panṣaga rẹ̀ bi si i:
nitori igbati o ri awọn ọkọnrin ti a ṣe li
àworan sara ogiri, ere awọn ara Kaldea ti a
fi ododó ṣe li àworan,
15 Ti a dì li àmure li ẹ̀gbẹ, ti nwọn
ṣe aṣejù ni rirẹ lawani ori wọn, gbogbo
wọn jẹ ajagun-kẹkẹ́ ti a ba ma wò, gẹgẹ
bi iṣe awọn ara Babiloni ti Kaldea, ilẹ ibi
wọn:
16 Bi o si ti fi oju rẹ̀ ri wọn, o fẹ wọn li
afẹjù, o si ran onṣẹ si wọn si Kaldea.
17 Awọn ara Babiloni si tọ̀ ọ wá lori
akete ifẹ, nwọn si fi panṣaga wọn bà a jẹ, a
si bà a jẹ pẹlu wọn, ọkàn rẹ̀ si ṣi kuro lọdọ
wọn.
18 Bayi li o tú idi panṣaga rẹ̀ silẹ, o si tú
ihòho rẹ̀ silẹ: nigbana li ọkàn mi ṣi kuro
lọdọ rẹ̀, gẹgẹ bi ọkàn mi ti ṣi kuro lọdọ
ẹ̀gbọn rẹ̀.
19 Sibẹsibẹ o mu panṣaga rẹ̀ bi si i, ni
pipè ọjọ ewe rẹ̀ si iranti, ninu eyi ti o ti ṣe
panṣaga ni ilẹ Egipti.
20 Nitoripe o fẹ awọn olufẹ wọn li afẹju,
ẹran-ara awọn ti o dabi ẹran-ara kẹtẹkẹtẹ,
ati irú awọn ẹni ti o dabi irú ẹṣin.
21 Bayi ni iwọ pe ìwa ifẹkufẹ ìgba ewe
rẹ wá si iranti, niti ririn ori ọmú rẹ lati
ọwọ́ awọn ara Egipti, fun ọmú ìgba ewe
rẹ.
22 Nitorina, iwọ Aholiba, bayi li Oluwa
Ọlọrun wi; Kiye si i, emi o gbe awọn olufẹ
rẹ dide si ọ, lọdọ awọn ti ọkàn rẹ ti ṣi, emi
o si mu wọn doju kọ ọ niha gbogbo.
23 Awọn ara Babiloni, ati gbogbo awọn
ara Kaldea, Pekodu, ati Ṣoa, ati Koa, ati
gbogbo awọn ara Assiria pẹlu wọn: gbogbo
wọn jẹ ọmọkọnrin ti o wunni, balogun ati
awọn olori, awọn ogboni ti o li okiki, gbo-
gbo wọn li o ngun ẹṣin.
24 Nwọn o si wá fi kẹkẹ́ ogun, kẹkẹ́ ẹrù,
ati kẹkẹ́ kekeke doju kọ ọ, ati pẹlu ìgbajọ
ọ̀pọ enia, awọn ti yio doju asà, ati apata,
ati akoro kọ ọ niha gbogbo: emi o si gbe
idajọ kalẹ niwaju wọn, nwọn o si da ọ lẹjọ
gẹgẹ bi idajọ wọn.
25 Emi o si doju owu mi kọ ọ, nwọn o
si fi irúnu ba ọ lò: nwọn o fá imu rẹ ati eti
rẹ; ati awọn ti o kù ninu rẹ yio ti ọwọ́ idà
ṣubu: nwọn o mu awọn ọmọ rẹ ọkọnrin,
ati awọn ọmọ rẹ obirin lọ, ati awọn ti o kù
ninu rẹ, li a o fi iná run.
26 Nwọn o si bọ aṣọ rẹ, nwọn o si mu
ohun ọṣọ daradara rẹ lọ.
27 Bayi li emi o jẹ ki ifẹkufẹ rẹ mọ kuro
lọdọ rẹ, ati panṣaga rẹ ti o mu ti ilẹ Egipti
wá; tobẽ, ti iwọ kì yio gboju rẹ soke si
wọn, bẽni iwọ kì yio si ranti Egipti mọ.
28 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Ki-
yesi i, emi o fi ọ le awọn ti iwọ korira lọwọ,
li ọwọ́ awọn ẹniti ọkàn rẹ ṣi:
29 Nwọn o si ba ọ lo ilo irira, nwọn o si
ko gbogbo iṣẹ rẹ lọ, nwọn o si fi ọ silẹ ni
ihoho ati ni goloto: ati ihoho panṣaga rẹ
li a o tu silẹ, ti ifẹkufẹ rẹ, ati panṣaga rẹ.
30 Emi o ṣe gbogbo nkan wọnyi si ọ,
nitori pe iwọ ti bá awọn keferi ṣe agbere
lọ, ati pe iwọ ti fi oriṣa wọn bà ara rẹ jẹ́.
31 Iwọ ti rìn li ọ̀na ẹ̀gbọn rẹ, nitorina li
emi o fi ago rẹ̀ le ọ lọwọ.
32 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Iwọ o mu
ninu ago ẹ̀gbọn rẹ ti o jin, ti o si tobi: a o
fi ọ rẹrin ẹlẹya, a o yọ ṣuti si ọ; o gbà
pupọ.
33 A o fi ọti pa ọ, a o si fi ikãnu kún ọ,
pẹlu ago iyanu ati idahoro, pẹlu ago Sama-
ria ẹ̀gbọn rẹ.
34 Iwọ o tilẹ mu u, iwọ o si fi ẹnu fa ọti
jade, iwọ o si fọ apãdi na, iwọ o si fà ọmú
ara rẹ tu, nitori mo ti sọ ọ, li Oluwa Ọlọ-
run wi.
35 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Nitoripe iwọ ti gbagbe mi ti o si ti sọ mi
si ẹhìn rẹ, nitorina iwọ rù ifẹkufẹ rẹ pẹlu
ati panṣaga rẹ,
36 Oluwa tun sọ fun mi pe; Ọmọ enia,
iwọ o ha dá Ahola ati Aholiba lẹjọ? nitõtọ
sọ irira wọn fun wọn;
37 Pe, nwọn ti ṣe panṣaga, ẹ̀jẹ si mbẹ
lọwọ wọn, ati nipasẹ oriṣa wọn ni nwọn ti
ṣe panṣaga, nwọn si ti jẹ ki awọn ọmọ wọn,
ti nwọn bi fun mi, kọja lãrin iná fun wọn,
lati run wọn.

Digitized by Google

38 Eyi ni nwọn si ṣe si mi; nwọn ti bà ibi mimọ́ mi jẹ li ọjọ kanna, nwọn sọ ọjọ isimi mi di aìlọwọ.

39 Nitoripe igbati nwọn pa awọn ọmọ wọn fun oriṣa wọn, nigbana ni nwọn wá ni ijọ kanna si ibi mimọ́ mi, lati sọ ọ di àilọwọ; si kiye si i, bayi ni nwọn ṣe lãrin ile mi.

40 Ati pẹlupẹlu, ti pe ẹnyin ranṣẹ pè awọn ọkọnrin lati okẽre wá, sọdọ awọn ti a ranṣẹ pè; si kiyesi i, nwọn de: fun ẹniti iwọ wẹ̀ ara rẹ, ti o si le tirõ, ti o si fi ohun ọṣọ́ ṣe ara rẹ li ọṣọ́.

41 Ti o si joko lori àkete daradara, a si tẹ́ tabili siwaju rẹ̀, lori eyi ti iwọ gbe turari mi ati ororó mi lé.

42 Ati ohùn ọ̀pọlọpọ enia, ti nwọn pa rọ́rọ wà lọdọ rẹ̀: ati pẹlu enia lasan li a mu awọn Sabeani lati aginjù wá, ti nwọn fi jufù si apá wọn, ati ade daradara si ori wọn.

43 Nigbana ni mo wi fun on ti o gbó ni panṣaga, Nwọn o ha bá a ṣe panṣaga nisisiyi, ati on pẹlu wọn?

44 Sibẹsibẹ wọn wọle tọ̀ ọ, bi nwọn ti iwọle tọ̀ obirin ti nṣe panṣaga: bẽni nwọn wọle tọ̀ Ahola ati Aholiba, awọn onifẹkufẹ obirin.

45 Ati awọn ọkọnrin olododo, nwọn o ṣe idajọ wọn, bi a ti iṣe idajọ awọn àgbere obirin, ati bi a ti iṣe idajọ awọn obirin ti o ta ẹjẹ silẹ; nitoripe àgbere ni nwọn, ẹjẹ si wà lọwọ wọn.

46 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun wi; emi o mu ẹgbẹ kan tọ̀ wọn wá, emi o si fi wọn fun wọn lati kó wọn lọ, ati lati bà wọn jẹ.

47 Ẹgbẹ na yio si sọ wọn li okuta, nwọn o si fi idà pa wọn; nwọn o pa awọn ọmọ wọn ọkọnrin, ati awọn ọmọ wọn obirin, nwọn o si fi iná kun ile wọn.

48 Bayi li emi o jẹ ki ìwa ifẹkufẹ mọ lãrin ilẹ na, ki a ba le kọ́ gbogbo obirin, ki nwọn má bà ṣe bi ifẹkufẹ nyin.

49 Nwọn o si san ẹsan ìwa ifẹkufẹ nyin si ori nyin, ẹnyin o si rù ẹ̀ṣẹ oriṣa nyin; ẹnyin o si mọ̀ pe emi li Oluwa Ọlọrun.

## ORI 24.

ỌRỌ Oluwa tun tọ̀ mi wá, li ọdun kẹsan, li oṣu kẹwa, li ọjọ kẹwa oṣu, wipe,

2 Ọmọ enia, iwọ kọ orukọ ọjọ na, ani ọjọ kanna yi: ọba Babiloni doju kọ Jerusalemu li ọjọ kanna yi:

3 Si pa owe si ọlọtẹ ilẹ na, si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi: Gbe ìkoko ka iná, gbe e kà a, si dà omi sinu rẹ̀ pẹlu:

4 Kó aján na jọ sinu rẹ̀, olukuluku aján ti o tobi, itan, ati apá, fi egungun ti o jọju kún inu rẹ̀.

5 Mu ninu agbo-ẹran ti o jọju, ko awọn egungun sabẹ rẹ̀, si jẹ ki o hó rere, si jẹ ki nwọn bọ̀ egungun rẹ̀ ninu rẹ̀.

6 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Egbé ni fun ilu ẹlẹjẹ na, fun ìkoko ti ifõfo rẹ̀ wà ninu rẹ̀, ti ifõfo rẹ̀ kò dá loju rẹ̀: mu u jade li aján li aján; máṣe dìbo nitori rẹ̀.

7 Nitori ẹjẹ rẹ̀ wà lãrin rẹ̀, o gbé e kà ori apata kan, kò tú u dà sori ilẹ, lati fi erupẹ bò o.

8 Ki o ba lè jẹ ki irúnu ki o de, lati gbẹsan; mo ti gbe ẹjẹ rẹ̀ kà ori apata kan, ki a má ba le bò o.

9 Nitorina, bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Egbe ni fun ilu ẹlẹjẹ na! Emi o tilẹ jẹ ki òkiti iná na tobi.

10 Ko igi jọ si i, ko iná jọ, jo ẹran na, fi turari dùn u; si jẹ ki egungun na jona.

11 Si gbe e kà ori ẹyín iná na lasan, ki idẹ rẹ̀ le gbona, ki o le pọ́n, ati ki ẽri rẹ̀ le di yiyọ́ ninu rẹ̀, ki ifõfo rẹ̀ le run.

12 On ti fi eke dá ara rẹ̀ lagara, ifõfo nla rẹ̀ kò si jade kuro lara rẹ̀: ifõfo rẹ̀ yio wà ninu iná.

13 Ninu ẽri rẹ̀ ni iwà ifẹkufẹ wà: nitori mo ti wẹ̀ ọ, iwọ kò si mọ́, a kì yio si tun wẹ̀ ọ kuro ninu ẽri rẹ mọ, titi emi o fi jẹ ki irúnu mi ba le ọ lori.

14 Emi Oluwa li o ti sọ ọ, yio si ṣẹ, emi o si ṣe e: emi kì yio pada sẹhìn, bẽni emi kì yio dasi, bẽni emi kì yio ronupiwada; gẹgẹ bi ọ̀na rẹ, ati gẹgẹ bi iṣe rẹ ni nwọn o da ọ lẹjọ, li Oluwa Ọlọrun wi.

15 Ọrọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,

16 Ọmọ enia, kiye si i, mo mu ifẹ oju rẹ kuro lọdọ rẹ, nipa lilù kan: ṣugbọn iwọ kò gbọdọ gbãwẹ, bẽni iwọ kò gbọdọ sọkun, bẽni omije rẹ kò gbọdọ ṣan silẹ.

17 Máṣe sọkun, máṣe gbãwẹ fun okú, wé lawàni sori rẹ, si bọ̀ bàta rẹ si ẹsẹ rẹ, máṣe bò ète rẹ, máṣe jẹ onjẹ enia.

18 Bẽni mo sọ fun awọn enia li owurọ: li aṣálẹ obirin mi si kú, mo si ṣe li owurọ bi a ti pá a li aṣẹ fun mi.

19 Awọn enia si sọ fun mi wipe, Iwọ kì yio ha sọ fun wa ohun ti nkan wọnyi jasi fun wa, ti iwọ ṣe bayi?

20 Mo si da wọn lohùn pe, Ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá wipe,

21 Sọ fun ile Israeli pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, kiyesi i emi o sọ ibi mimọ́ mi di aimọ́, titayọ agbara nyin, ifẹ oju nyin, ikãnu ọkàn nyin, ati ọmọ nyin ọkọnrin ati



Digitized by Google

ọmọ nyin obirin, ti ẹnyin ti fi silẹ, yio ti
ipa idà ṣubu.
22 Ẹnyin o si ṣe bi emi ti ṣe: ẹnyin kò
ni bò ète nyin, bẹ̃ni ẹ kò ni jẹ onjẹ enia.
23 Lawani nyin yio si wà li ori nyin, ati
bàta nyin li ẹsẹ nyin: ẹnyin kò ni gbãwẹ,
bẹ̃ni ẹ kò ni sọkun: ṣugbọn ẹnyin o ma
joro nitori aiṣedẽde nyin, ẹ o si ma ṣọfọ ẹni-
kan si ẹnikeji.
24 Bayi ni Esekieli jẹ àmi fun nyin:
gẹgẹ bi gbogbo ohun ti o ṣe, li ẹ o si ṣe
nigbati eyi bá si de, ẹnyin o si mọ̀ pe emi
li Oluwa Ọlọrun:
25 Pẹlupẹlu, iwọ ọmọ enia, kì yio ha ṣe
pe, ni ijọ na nigbati mo ba gbà agbara wọn,
ayọ̀ ogo wọn, ifẹ oju wọn, ati eyiti nwọn
gbe ọkàn wọn le, ọmọ wọn ọkọnrin, ati ọmọ
wọn obirin, kuro lọdọ wọn,
26 Ti ẹniti ti o ba sálà nijọ na, yio tọ̀ ọ
wá, lati jẹ ki iwọ ki o fi eti ara rẹ gbọ́?
27 Li ọjọ na li ẹnu rẹ yio ṣi si ẹni ti o
sala, iwọ o si sọ̀rọ, iwọ kì yio si yadi mọ:
iwọ o si jẹ àmi fun wọn: nwọn o si mọ̀ pe
emi li Oluwa.

## ORI 25.

ỌRỌ Oluwa tún tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, doju kọ awọn ara Am-
moni, si sọtẹlẹ si wọn;
3 Si wi fun awọn ara Ammoni pe, Ẹ gbọ́
ọ̀rọ Oluwa Ọlọrun: Bayi ni Oluwa Ọlọrun
wi; Nitori ti iwọ wipe, Ahá, si ibi mimọ́
mi, nigbati o di àilọwọ, ati si ilẹ Israeli,
nigbati o di ahoro; ati si ilẹ Juda, nigbati
nwọn lọ ni ìgbekun;
4 Kiyesi i, nitorina emi o fi ọ le awọn
enia ilà-õrùn lọwọ fun ini, nwọn o si gbe
ãfin wọn kalẹ ninu rẹ, nwọn o si ṣe ibugbe
wọn ninu rẹ: nwọn o jẹ eso rẹ, nwọn o si
mu wàra rẹ.
5 Emi o si sọ Rabba di ibujẹ fun iba-
kasiẹ, ati awọn ọmọ Ammoni di ibùsun
fun agbo-ẹran: ẹnyin o si mọ̀ pe emi li
Oluwa.
6 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Ni-
toriti iwọ ti pa atẹ́wọ, ti o si ti fi ẹsẹ kì ilẹ,
ti o si yọ̀ li ọkàn pẹlu gbogbo aránkan rẹ si
ilẹ Israeli:
7 Kiye si i, nitorina, emi o nà ọwọ́ mi le
ọ, emi o si fi ọ fun awọn keferi fun ikogun;
emi o si ke ọ kuro lãrin awọn enia, emi o
si jẹ ki o ṣegbé kuro ninu ilẹ gbogbo: emi
o pa ọ run; iwọ o si mọ̀ pe emi li Oluwa.
8 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Nitoripe
Moabu ati Seiri wipe, Kiye si i, ile Juda
dabi gbogbo awọn keferi;
9 Nitorina, kiye si i, emi o ṣi ìha Moabu
kuro lati awọn ilu gbogbo, kuro ninu awọn
ilu rẹ̀ ti o wà li àgbegbe rẹ̀, ogo ilẹ na,
Bet-jeṣimoti, Baali-meoni, ati Kiri-ataimu,
10 Fun awọn ọmọ ìla-õrun, pẹlu awọn
ara Ammoni, emi o si fi wọn fun ni ni iní;
ki a má ba ranti awọn ara Ammoni lãrin
orilẹ-ède mọ.
11 Emi o si mu idajọ ṣẹ si Moabu lara,
nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.
12 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Nitoripe
Edomu ti huwà si ile Juda nipa gbigba
ẹsan, o si ti ṣẹ̀ gidigidi, o si gbẹ̀san ara rẹ̀
lara wọn.
13 Nitorina, bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
emi pẹlu yio nawọ mi si Edomu, emi o si
ke enia ati ẹranko kuro ninu rẹ̀; emi o si
sọ ọ di ahoro lati Temani; ati awọn ti
Dedani, yio ti ipa idà ṣubu.
14 Emi o si gbe ẹ̀san mi le ori Edomu
lati ọwọ́ Israeli enia mi: nwọn o si ṣe ni
Edomu gẹgẹ bi ibinu mi, ati gẹgẹ bi irúnu
mi; nwọn o si mọ̀ ẹ̀san mi, li Oluwa
Ọlọrun wi.
15 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Nitori ti
awọn ara Filistia ti lò ilo ẹsan, ti nwọn si
ti fi ọkàn ti o kún fun arankàn gbẹsan,
lati pa a run, nitori irira atijọ.
16 Nitorina, bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Kiyesi i, emi o nà ọwọ́ mi le awọn ara
Filistia, emi o si ke awọn ara Keriti kuro,
emi o si run awọn iyokù ti eti okun.
17 Emi o si san ẹsan nla lara wọn nipa
ibáwi gbigbona; nwọn o si mọ̀ pe, emi li
Oluwa, nigbati emi o gbe ẹsan mi le wọn.

## ORI 26.

O SI ṣe li ọdun kọkanla, li oṣu ikini, ọ̀rọ
Oluwa tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, nitoriti Tire ti sọ̀rọ si Jeru-
salemu, pe, Aha, a fọ́ eyiti iṣe bode awọn
orilẹ-ède: a yi i pada si mi, emi o di kikún,
on di ahoro:
3 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
kiyesi i, mo doju kọ ọ, iwọ Tire, emi o si
jẹ ki orilẹ-ède pupọ dide si ọ, gẹgẹ bi okun
ti igbé riru rẹ̀ soke.
4 Nwọn o si wó odi Tire lulẹ, nwọn o si
wó ile iṣọ́ rẹ̀ lulẹ; emi o si há erùpẹ rẹ̀
kuro lara rẹ̀, emi o si ṣe e bi ori apata.
5 Yio jẹ ibi ninà awọn si lãrin okun:
nitori mo ti sọ ọ, li Oluwa Ọlọrun wi: yio
si di ikogun fun awọn orilẹ-ède.
6 Ati awọn ọmọbirin rẹ̀ ti o wà li oko,
li a o fi idà pa; nwọn o si mọ̀ pe emi li
Oluwa.

Digitized by Google

7 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Kiyesi i, emi o mu Nebukadnessari ọba
Babiloni, ọba awọn ọba, wá si Tire, lati
ariwa, pẹlu ẹṣin, ati kẹkẹ́ ogun, ati ẹlẹṣin,
ati ẹgbẹ́, ati enia pupọ.
8 Yio fi idà pa awọn ọmọbirin rẹ li oko:
yio si kọ kũkũ tì ọ, yio si mọ odi tì ọ, yio
si gbe apata soke si ọ.
9 Yio si gbe ohun-ẹrọ ogun tì odi rẹ, yio
si fi ãke rẹ̀ wó ile-iṣọ́ rẹ lulẹ.
10 Nitori ọ̀pọ awọn ẹṣin rẹ̀ ẽkuru wọn
yio bò ọ: odi rẹ yio mì nipa ariwo awọn
ẹlẹṣin, ati kẹkẹ́, ati kẹkẹ́ ogun, nigbati yio
wọ̀ inu odi rẹ lọ, gẹgẹ bi enia ti wọ̀ inu ilu
ti a fọ́.
11 Pátakò ẹṣin rẹ̀ ni yio fi tẹ̀ gbogbo ìta
rẹ mọlẹ: on o fi idà pa awọn enia rẹ, ati
ọwọ̀n lile rẹ yio wó lulẹ.
12 Nwọn o si fi ọrọ̀ rẹ ṣe ìkogun, ati òwo
rẹ ṣe ijẹ ogun; nwọn o si wo odi rẹ lulẹ,
nwọn o si bà ile rẹ daradara jẹ: nwọn o si
ko okuta rẹ, ati ìti igi-ìkọle rẹ, ati erùpẹ
rẹ, dà si ãrin omi.
13 Emi o si mu ariwo orin rẹ dakẹ; ati
iró dùru rẹ li a kì yio gbọ́ mọ.
14 Emi o si ṣe ọ bi ori apáta; iwọ o si
jẹ ibi lati nà àwọ̀n le lori; a kì yio kọ́ ọ
mọ: nitori emi Oluwa li o ti sọ ọ, li Oluwa
Ọlọrun wi.
15 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi si Tire;
awọn erekùṣu kì yio ha mì-titi nipa iró
iṣubu rẹ, nigbati awọn ti o gbọgbẹ́ kigbe,
nigbati a ṣe ipani li ãrin rẹ?
16 Nigbana li awọn ọmọ-alade okun
yio sọ̀kalẹ kuro lori itẹ́ wọn, nwọn o si
pa aṣọ igunwà wọn tì, nwọn o si bọ́ ẹ̀wu
oniṣẹ-ọnà wọn: nwọn o fi ìwariri bò ara
wọn; nwọn o joko lori ilẹ, nwọn o si wariri
nigbagbogbo, ẹnu o si yà wọn si ọ.
17 Nwọn o si pohunrere-ẹkun fun ọ,
nwọn o si wi fun ọ pe, Bawo li ati pa ọ
run, iwọ ti awọn èro okun ti ngbe inu rẹ̀,
ilu olokiki, ti o lagbara li okun, on ati
awọn ti o gbe inu rẹ̀, ẹniti o mu ẹ̀ru wọn
wá sara gbogbo awọn ti o pàra ninu rẹ!
18 Nisisiyi ni awọn erekùṣu yio warìri li
ọjọ iṣubu rẹ; nitõtọ, awọn erekùṣu ti o wà
ninu okun li a o yọ lẹnu nigba atilọ rẹ.
19 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun wi: Nigbati
emi o sọ ọ di ahoro ilu, gẹgẹ bi ilu
wọnni ti a kò gbe inu wọn; nigbati emi o
si mu ibú wá sori rẹ, ati omi nla yio si
bò ọ.
20 Nigbati emi o bá mu ọ walẹ pẹlu
awọn ti o sọkalẹ sinu ihò, pẹlu awọn enia
igbãni, ti emi o si gbe ọ kà ibi isalẹ ilẹ
aiye, ni ibi ahoro igbãni, pẹlu awọn ti o
sọkalẹ lọ si ihò, ki a máṣe gbe inu rẹ mọ́:
emi o si gbe ogo kalẹ ni ilẹ awọn alãye;
21 Emi o si ṣe ọ ni ẹ̀ru, iwọ kì yio si si
mọ́: bi a tilẹ wá ọ, sibẹ a kì yio tun ri ọ
mọ́, li Oluwa Ọlọrun wi.

## ORI 27.

ỌRỌ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
2 Nisisiyi, iwọ ọmọ enia, pohunrere
ẹkun fun Tire;
3 Ki o si wi fun Tire pe, Iwọ ti a tẹ̀do si
ẹnu-ọ̀na okun, oniṣòwo awọn orilẹ-ède fun
ọ̀pọlọpọ erekùṣu, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Iwọ Tire, iwọ ti wipe, emi pé li ẹwà.
4 Àlà rẹ wà li ãrin okun, awọn ọ̀mọle rẹ
ti mu ẹwà rẹ pé.
5 Nwọn ti fi apako firi ti Seniri kàn
gbogbo ọkọ̀ rẹ, nwọn ti mu kedari ti Lebanoni
wà lati fi ṣe opó ọkọ̀ fun ọ.
6 Ninu igi oaku ti Baṣani ni nwọn ti fi
gbẹ́ àjẹ rẹ; ijoko rẹ ni nwọn fi ehin-erin ṣe
pelu igi boksi lati erekuṣu Kittimu wá.
7 Ọ̀gbọ daradara iṣẹ-ọnà lati Egipti wá
li eyiti iwọ ta fi ṣe igbokun rẹ; aṣọ aláro
ati purpili lati erekuru Eliṣa wá li eyiti a
fi bò ọ.
8 Awọn ara ilu Sidoni ati Arfadi ni awọn
ara ọkọ̀ rẹ̀: awọn ọlọgbọn rẹ, Iwọ Tire, ti
o wà ninu rẹ, li awọn atọkọ̀ rẹ.
9 Awọn àgba Gebali, ati awọn ọlọgbọn
ibẹ̀, wà ninu rẹ bi adikọ̀ rẹ: gbogbo ọkọ̀
okun pẹlu awọn ara ọkọ̀ wọn wà ninu rẹ
lati ma ṣòwo rẹ.
10 Awọn ti Persia, ati ti Ludi, ati ti
Futi, wà ninu ogun rẹ, awọn ologun rẹ:
nwọn fi apata ati ìbori-ogun kọ́ ninu rẹ;
nwọn fi ẹwà rẹ hàn.
11 Awọn enia Arfadi, pẹlu awọn ogun
rẹ, wà lori odi rẹ yika, ati awọn akọ-jamã
wà ni ile-iṣọ rẹ: nwọn fi apata kọ́ sara odi
rẹ yika; nwọn ti ṣe ẹwà rẹ pé.
12 Tarṣiṣi ni oniṣòwo rẹ nitori ọ̀pọlọpọ̀
ọrọ̀ rẹ; pẹlu fadakà, irin, tánganran, ati
ojé, nwọn ti ṣòwo li ọjà rẹ.
13 Jafani, Tubali, ati Meṣeki, awọn li
awọn oniṣòwo rẹ: nwọn ti fi ẹrú ati ohunèlò
idẹ ṣòwo li ọjà rẹ.
14 Awọn ti ile Togarma fi ẹṣin, ati ẹlẹsin
ati ìbaka sòwo li ọjà rẹ.
15 Awọn enia Dedani li awọn oniṣòwo
rẹ; ọ̀pọlọpọ erekuṣu ni mba ọ ṣòwo, nwọn
mu ehin-erin ati igi eboni wá fun ọ lati rà.
16 Siria li oniṣòwo rẹ nitori ọ̀pọlọpọ iṣẹ
ọwọ́ rẹ: nwọn ntà emeraldi li ọjà rẹ, pẹlu

Digitized by Google

purpili, ati iṣẹ oniṣẹ-ọnà, ati ògbọ daradara,
ati iyùn, ati agate.
17 Juda ati ilẹ Israeli, awọn li awọn
oniṣòwo rẹ, alikama ti Minniti, ati Panna-
gi, ati oyin, ati ororo, ati balmu, ni nwọn
fi ná ọjà rẹ.
18 Damasku li oniṣòwo rẹ nitori ọ̀pọ-
lọpọ ohun ọjà ti o ṣe, nitori ọ̀pọlọpọ ọrọ̀;
ni ọtiwaini ti Helboni, ati irun-agutan
funfun.-
19 Dani pẹlu ati Jafani lati Usali ngbé
ọjà rẹ: irin didán, kassia, ati kalamu wà
li ọjà rẹ.
20 Dedani ni oniṣòwo rẹ ni aṣọ ibori fun
kẹkẹ́.
21 Arabia, ati gbogbo awọn ọmọ-alade
Kedari, awọn ni awọn oniṣòwo rẹ, ni ọdọ-
agutan, ati agbò, ati ewurẹ; ninu wọnyi
ni nwọn ṣe oniṣòwo rẹ.
22 Awọn oniṣòwo Ṣeba ati Rama, awọn
li awọn oniṣòwo rẹ: nwọn tà onirũru turari
daradara li ọjà rẹ, ati pẹlu onirũru okuta
oniyebiye, ati wura.
23 Harani, ati Kanneh, ati Edeni, awọn
oniṣòwo Ṣeba, Assuru, ati Kilmadi, ni awọn
oniṣòwo rẹ.
24 Wọnyi li awọn oniṣòwo rẹ li onirũru
nkan, ni aṣọ alaro, ati oniṣẹ-ọnà, ati apoti
aṣọ oniyebiye, ti a fi okùn dì, ti a si fi igi
kedari ṣe, ninu awọn oniṣòwo rẹ.
25 Awọn ọkọ Tarṣiṣi ni èro li ọjà rẹ: a
ti mu ọ rẹ̀ si i, a si ti ṣe o logo li ãrin
okun.
26 Awọn atukọ̀ rẹ ti mu ọ wá sinu omi
nla: ẹfũfu ilà-õrun ti fọ́ ọ li ãrin okun.
27 Ọrọ̀ rẹ ati ọjà rẹ, ọjà tità rẹ, awọn
atukọ̀ rẹ, ati atọ́kọ̀ rẹ, adikọ̀ rẹ, ati awọn
alábarà rẹ, ati gbogbo awọn ologun rẹ, ti o
wà ninu rẹ, ati ninu gbogbo ẹgbẹ́ rẹ, ti o
wà li ãrin rẹ, yio ṣubu li ãrin okun li ọjọ
iparun rẹ.
28 Awọn ilẹ àgbègbe yio mì nitori irò
igbe awọn atọkọ̀ rẹ.
29 Gbogbo awọn alajẹ̀, awọn atukọ̀, ati
awọn atọ́kọ̀ okun yio sọkalẹ kuro ninu ọkọ̀
wọn, nwọn o duro lori ilẹ.
30 Nwọn o si jẹ ki a gbọ́ ohùn wọn si ọ,
nwọn o si kigbe kikoro, nwọn o si kù ekuru
sori ara wọn, nwọn o si yi ara wọn ninu
ẽru:
31 Nwọn o si fari wọn patapata fun ọ,
nwọn o si fi aṣọ-àpo di ara wọn, nwọn o si
sọkun fun ọ ni ikorò aiya, pẹlu ohùnrére
ẹkun kikorò.
32 Ati ninu arò wọn ni nwọn o si pohùn-
rére ẹkún fun ọ, nwọn o si pohùnrére ẹkún
sori rẹ, wipe, Ta li o dabi Tire, eyiti a pa-
run li ãrin okun?
33 Nigbati ọjà-tità rẹ ti okun jade wá,
iwọ tẹ́ orilẹ-ède pupọ lọrun; iwọ fi ọ̀pọlọpọ
ọrọ̀ rẹ, ati ọjà rẹ, sọ awọn ọba aiye di
ọlọrọ̀.
34 Nisisiyi ti okun fọ́ ọ bajẹ̀ ninu ibú
omi, nitorina òwo rẹ, ati gbogbo ẹgbẹ́ rẹ li
ãrin rẹ, li o ṣubu.
35 Ẹnu yio yà gbogbo awọn olugbe ere-
kuṣu wọnni si ọ, awọn ọba wọn yio si dijì,
iyọnu yio yọ li oju wọn.
36 Awọn oniṣòwo lãrin awọn orilẹ-ède
yio dún bi ejò si ọ; iwọ o si jẹ ẹ̀ru, iwọ kì
yio si si mọ́ lailai.

## ORI 28.

ỌRỌ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, sọ fun ọmọ-alade Tire
pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Nitori ti
ọkàn rẹ gbe soke, ati ti iwọ si wipe, Ọlọrun
li emi, emi joko ni ibujoko Ọlọrun, larin
okun; ṣugbọn enia ni iwọ, iwọ kì isi ṣe
Ọlọrun, bi o tilẹ gbe ọkàn rẹ soke bi ọkàn
Ọlọrun.
3 Wo o, iwọ sa gbọn ju Danieli lọ; kò
si si ohun ikọ̀kọ ti o le fi ara sin fun ọ.
4 Ọgbọ́n rẹ ati oye rẹ li o fi ni ọrọ̀, o si
ti ni wura ati fadáka sinu iṣura rẹ:
5 Nipa ọgbọ́n rẹ nla ati nipa òwo rẹ li o
ti fi sọ ọrọ̀ rẹ di púpọ, ọkàn rẹ si gbe soke
nitori ọrọ̀ rẹ.
6 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Nitoriti o ti ṣe ọkàn rẹ bi ọkàn Ọlọrun;
7 Kiyesi i, nitorina emi o mu alejo wá
ba ọ, ẹlẹ̀ru ninu awọn orilẹ-ède: nwọn o si
fà idà wọn yọ si ẹwà ọgbọ́n rẹ, nwọn o si
bà didán rẹ jẹ.
8 Nwọn o mu ọ sọkalẹ wá sinu ihò, iwọ
o si kú ikú awọn ti a pa li ãrin okun.
9 Iwọ ha le sọ sibẹ niwaju ẹni ti npa ọ,
pe, Emi li Ọlọrun? ṣugbọn enia ni iwọ, o
kì yio si jẹ Ọlọrun, lọwọ ẹniti npa ọ.
10 Iwọ o kú ikú awọn alaikọlà lọwọ
awọn alejo: nitori emi li o ti sọ ọ, li Oluwa
Ọlọrun wi.
11 Ọrọ Oluwa si tun tọ̀ mi wá, wipe,
12 Ọmọ enia, pohùnrére sori ọba Tire,
ki o si wi fun u pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun
wi; Iwọ fi edidi dí iye na, o kún fun ọgbọ́n,
o si pé li ẹwà.
13 Iwọ ti wà ni Edeni ọgbà Ọlọrun;
oniruru okuta iyebiye ni ibora rẹ, sardiu,
topasi, ati diamondi, berili, oniki, ati jas-
peri, safire, emeraldi, ati karbunkili, ati

Digitized by Google

wura : işẹ ìlu rẹ ati ti fère rẹ li a pèse ninu
rẹ li ọjọ ti a dá ọ.
14 Iwọ ni kerubu ti a nà ti o si bò ; emi
si ti gbe ọ kalẹ : iwọ wà lori oke mimọ
Ọlọrun ; iwọ ti rìn soke rìn sodò lãrin
okuta iná.
15 Iwọ pé li ọnà rẹ lati ọjọ ti a ti dá ọ,
titi a fi ri aişedẽde ninu rẹ.
16 Nitori ọ̀pọlọpọ òwo rẹ, nwọn ti fi
iwà-ipa kún ãrin rẹ, iwọ si ti şẹ̀ : nitorina
li emi o şe sọ ọ nù bi ohun ailọ̀wọ kuro li
oke Ọlọrun : emi o si pa ọ run, iwọ kerubu
ti o bò, kuro lãrin okuta iná.
17 Ọkàn rẹ gbe soke nitori ẹwà rẹ, o ti
bà ọgbọ́n rẹ jẹ nitori dídan rẹ ; emi o bì ọ
lulẹ, emi o gbe ọ kalẹ niwaju awọn ọba, ki
nwọn ba le wò ọ.
18 Iwọ ti bà ibi mimọ́ rẹ jẹ nipa ọ̀pọlọpọ
aişedẽde rẹ, nipa aişedẽde òwo rẹ ; nitorina
emi o mu iná jade lati ãrin rẹ wá, yio jó ọ
run, emi o si sọ ọ di ẽrú lori ilẹ loju gbogbo
awọn ti o wò ọ :
19 Gbogbo awọn ti o mọ̀ ọ lãrin awọn
orilẹ-ède li ẹnu o yà si ọ : iwọ o jẹ ẹ̀ru, iwọ
kì yio si si mọ́ lailai.
20 Ọ̀rọ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
21 Ọmọ enia, gbé oju rẹ si Sidoni, ki o si
sọtẹlẹ si i,
22 Si wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi ;
Sa wò o, Emi doju kọ ọ, iwọ Sidoni ; a o
si şe mi logo li ãrin rẹ, nwọn o si mọ̀ pe
emi li Oluwa, nigbati emi o bá ti mu idajọ
mi şẹ ninu rẹ̀, ti a o si yà mi si mimọ́ ninu
rẹ̀.
23 Emi o si rán àjakálẹ àrun sinu rẹ̀, ati
ẹjẹ ni igboro rẹ̀ ; a o sí fi idà pa awọn ti a
şá li ọgbẹ li ãrin rẹ̀ lori rẹ̀ nihà gbogbo ;
nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.
24 Kì yio si si ẹgún ti ngún ni fun ile
Israeli mọ́, tabi ẹgún bibani ninu jẹ́ ti gbo-
gbo awọn ti o yi wọn ká, ti o si şãtá wọn ;
nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa Ọlọrun.
25 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, Nigbati emi
o bá ti kó ile Israeli jọ kuro lãrin awọn
orilẹ-ède ti a tú wọn ká si, ti a o si yà mi
si mimọ́ ninu wọn loju awọn keferi, nigba-
na ni nwọn o gbé ilẹ wọn ti mo ti fi fun
Jakobu iranşẹ mi.
26 Nwọn o si ma gbé inu rẹ̀ ni ibalẹ-
aiya, nwọn o si kọ́ ile, nwọn o si gbìn ọgbà
àjara ; nitõtọ, nwọn o wà ni ibalẹ-aiya,
nigbati emi bá ti mu idajọ mi şẹ si ara
awọn ti ngàn wọn yi wọn kakiri, nwọn o si
mọ̀ pe emi li Oluwa Ọlọrun wọn.

## ORI 29.

LI ọdun kẹwa, li oşù kẹwa, li ọjọ kejila
oşù, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, kọ oju rẹ si Farao ọba
Egipti, si sọtẹlẹ si i, ati si gbogbo Egipti :
3 Sọ̀rọ, ki o si wipe, Bayi li Oluwa
Ọlọrun wi ; Kiyesi i, emi doju kọ ọ ; Farao
ọba Egipti, dragoni nla ti o dubulẹ li ãrin
awọn odò rẹ̀, eyiti o ti wipe, Ti emi li odò
mi, emi li o si ti wà a fun ara mi.
4 Şugbọn emi o fi ìwọ kọ́ ọ li ẹ̀rẹkẹ́, emi
o si jẹ ki ẹja odò rẹ ki o lẹ mọ́ ipẹ́ rẹ, emi
o si mu ọ kuro li ãrin odò rẹ, ati gbogbo
ẹja odò rẹ yio lẹ mọ́ ipẹ́ rẹ.
5 Emi o si sọ ọ nù si aginjù, iwọ ati
gbogbo ẹja odò rẹ : iwọ o şubu ni gbangba
oko : a kì yio si kó ọ jọ, bẽli a kì yio si şà
ọ jọ : emi ti fi ọ şe onjẹ fun awọn ẹranko
igbẹ́, ati fun awọn ẹiyẹ oju ọrun.
6 Gbogbo awọn olugbé Egipti yio mọ̀ pe
emi li Oluwa, nitori nwọn ti jẹ́ ọpá ìye fun
ile Israeli.
7 Nigbati nwọn dì ọ lọwọ mu, iwọ fọ́, o
si ya gbogbo èjiká wọn : nigbati nwọn si fi
ara tì ọ, iwọ şẹ́, o si mu gbogbo ẹgbẹ́ wọn
gbọ̀n.
8 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi,
Kiyesi i, emi o mu idà kan wá sori rẹ, ti
yio ké enia ati ẹranko kuro ninu rẹ.
9 Ilẹ Egipti yio si di aginjù yio si di
ahoro ; nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa :
nitori ti o ti wipe, Odò na temi ni, emi li
o si ti wà a.
10 Nitorina, kiyesi i, emi dojukọ ọ, mo
si dojukọ odò rẹ, emi o si sọ ilẹ Egipti di
ahoro patapata, lati Migdoli lọ de Siene
ati titi de ẹkùn Etiopia.
11 Ẹsẹ enia kì yio kọja li ãrin rẹ̀, bẽni
ẹsẹ ẹrankẹran kì yio kọja li ãrin rẹ̀, bẽni a
kì yio tẹ̀ ẹ dó li ogoji ọdun.
12 Emi o si sọ ilẹ Egipti di ahoro li ãrin
awọn ilẹ ti o di ahoro, ati ilu rẹ̀ yio si di
ahoro li ãrin awọn ilu ti o di ahoro li ogoji
ọdun : emi o si tú awọn ara Egipti ká
sãrin gbogbo orilẹ-ède, emi o si tú wọn ká
sãrin gbogbo ilẹ.
13 Şugbọn bayi li Oluwa Ọlọrun wi ;
Lẹhin ogoji ọdun li emi o ko awọn ara
Egipti jọ lati ọdọ awọn enia nibiti a ti tú
wọn ká si :
14 Emi o si tun mu igbèkun Egipti pada
bọ̀, emi o si mu wọn pada si ilẹ Patrosi, si
ilẹ ibí wọn, nwọn o si wà nibẹ bi ijọba ti a
rẹ̀ silẹ.
15 Yio si jẹ ijọba ti a rẹ̀lẹ jù ninu awọn

ijọba; bẽni kì yio si gbe ara rẹ̀ ga mọ́ sori
awọn orilẹ-ède: nitori emi o dín wọn kù,
ti nwọn kì yio fi ṣe olori awọn orilẹ-ède
mọ́.
16 Kì yio si jẹ igbẹkẹle fun ile Israeli
mọ́, ti o mu aiṣedẽde wọn wá si iranti,
nigbati nwọn o ba wò wọn: ṣugbọn nwọn
o mọ̀ pe emi li Oluwa Ọlọrun.
17 O si ṣe li ọdun kẹtadilọgbọ̀n, li oṣù
ikini, li ọjọ ikini oṣù, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá,
wipe,
18 Ọmọ enia, Nebukaddressari ọba Babiloni
mu ki ogun rẹ̀ sìn irú nla si Tire:
gbogbo ori pá, ati gbogbo èjiká bó: sibẹsibẹ
on, ati awọn ogun rẹ̀, kò ri owo ọ̀ya
gbà, lati Tire fun irú ti o ti sìn si i:
19 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Kiyesi i, emi o fi ilẹ Egipti fun Nebukaddressari
ọba Babiloni; yio si kó awọn ọ̀pọlọpọ
enia rẹ̀, ati ikógun rẹ̀, ati ijẹ rẹ̀; yio
si jẹ owo ọ̀ya fun awọn ogun rẹ̀.
20 Mo ti fi ilẹ Egipti fun u, fun irú ti o
sìn si i, nitoriti nwọn ṣiṣẹ́ fun mi, li Oluwa
Ọlọrun wi.
21 Li ọjọ na li emi o mu ki iwo Israeli
rú jade, emi o si fun ọ ni iṣínu li ãrin wọn;
nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.

ORI 30.

ỌRỌ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, sọtẹlẹ ki o si wipe, Bayi
li Oluwa Ọlọrun wi; Ẹ wu, Egbé fun ọjọ
na!
3 Nitori ọjọ na sunmọ tosí, ani ọjọ Oluwa
sunmọ tosi, ọjọ ikũkũ ni; yio jẹ akoko
ti awọn keferi.
4 Idà yio si wá sori Egipti, irora nla yio
wà ni Etiopia, nigbati awọn ti a pa yio
ṣubu ni Egipti, nwọn o si mu ọ̀pọlọpọ enia
rẹ̀ lọ kuro, ipilẹ rẹ̀ yio si wó lulẹ.
5 Etiopia, ati Libia, ati Lidia, ati gbogbo
awọn olùranlọ́wọ, ati Kubu, ati awọn
enia ilẹ na ti o mulẹ yio ti ipa idà ṣubu
pẹlu wọn.
6 Bayi li Oluwa wi; Awọn pẹlu ti nwọn
gbe Egipti ró yio ṣubu; ati igberaga agbara
rẹ̀ yio sọkalẹ: lati Migdoli lọ de Siene ni
awọn o ti ipà idà ṣubu ninu rẹ̀, li Oluwa
Ọlọrun wi.
7 Nwọn o si di ahoro li ãrin awọn ilẹ ti
o di ahoro, ilu rẹ̀ yio si wà li àrin awọn ilu
ti o di ahoro.
8 Nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa, nigbati
mo bá gbe iná kalẹ ni Egipti, ti gbogbo
awọn olùranlọ́wọ rẹ̀ bá parun.
9 Li ọjọ na ni onṣẹ yio lọ lati ọdọ mi
ninu ọkọ̀, lati dẹruba Etiopia ti o wà li
alafia, irora yio wá sori wọn gẹgẹ bi li ọjọ
Egipti: kiyesi i, o de.
10 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; emi o si
ṣe ki ọ̀pọlọpọ enia Egipti ki o ti ipa ọwọ́
Nebukaddressari ọba Babiloni dínkù.
11 On ati enia rẹ̀ pẹlu rẹ̀, ẹ̀ru awọn orilẹ-
ède, li a o mu wá pa ilẹ na run: nwọn o si
fà idà wọn yọ si Egipti, nwọn o si fi awọn
ti a pa kún ilẹ na.
12 Emi o mu gbogbo odò wọn gbẹ, emi
o si tà ilẹ na si ọwọ́ awọn enia buburu;
emi o si ti ipa ọwọ́ awọn alejo sọ ilẹ wọn di
ahoro, ati ẹkún rẹ̀: Emi Oluwa li o ti sọ ọ.
13 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; emi o pa
awọn oriṣa run pẹlu, emi o si jẹ ki ere wọn
tán ni Nofi; kì yio si si ọmọ-alade kan ni
ilẹ Egipti mọ́: emi o si fi ẹ̀ru si ilẹ Egipti.
14 Emi o si sọ Patrosi di ahoro, emi o si
gbe iná kalẹ ni Soani, emi o si mu idajọ ṣẹ
ni No.
15 Emi o si dà irúnu mi si ori Sini,
agbara Egipti; emi o si ké ọ̀pọlọpọ enia
No kuro.
16 Emi o si gbe iná kalẹ ni Egipti, Sini
yio ni irora nla, a o si fà No ya pẹ́rẹpẹ̀rẹ,
Nofi yio si ni ipọnju lojojumọ.
17 Awọn ọdọmọkọnrin Afeni ati Pibeseti
yio ti ipa idà ṣubu: ati awọn wọnyi yio lọ
si igbèkun.
18 Ọjọ yio si ṣõkun ni Tehafnehesi,
nigbati emi bá dá àjaga ọrùn Egipti nibẹ:
ọṣọ́ agbara rẹ̀ yio tán ninu rẹ̀: bi o ṣe tirẹ̀
ni, ikũkũ yio bò on, ati awọn ọmọ rẹ̀ obirin
yio lọ si igbèkun.
19 Bayi li emi o mu idajọ ṣẹ ni Egipti:
nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.
20 O si ṣe li ọdun kọkanlá, li oṣù kini,
li ọjọ keje oṣù, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá, wipe,
21 Ọmọ enia, emi ti ṣẹ apá Farao ọba
Egipti; si kiyesi i, a kì yio dì i ki o ba le
san, bẽni a kì yio fi igi si i lati dì i ki o ba
lagbara lati di idà mu.
22 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi:
Kiyesi i, emi dojukọ Farao ọba Egipti, emi
o si ṣẹ́ apá rẹ̀, eyi ti o le, ati eyiti o ṣẹ́; emi
o si jẹ ki idà bọ́ kuro li ọwọ́ rẹ̀.
23 Emi o si tú awọn ara Egipti ká sãrin
awọn orilẹ-ède, emi o si tú wọn ká sãrin
ilẹ.
24 Emi o si mu apá ọba Babiloni le, emi
o si fi idà mi si ọwọ́ rẹ̀: ṣugbọn emi o ṣẹ́
apá Farao, yio si ma kerora niwaju rẹ̀ bi
ikérora ọkọnrin ti a ṣá li aṣápa.
25 Ṣugbọn emi o mu apá ọba Babiloni le,
apá Farao yio si rọ; nwọn o si mọ̀ pe emi

Digitized by Google

li Oluwa, nigbati emi o ba fi idà mi si ọwọ́
ọba Babiloni, ki o le ba nà' a sori ilẹ Egipti.
26 Emi o si tú awọn ara Egipti ká sãrin
awọn orilẹ-ède, emi o si tú wọn ká sãrin
awọn ilẹ; nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.

## ORI 31.

OSI ṣe li ọdun kọkanlá, li oṣù kẹta, li
ọjọ ekini oṣù, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá,
wipe,
2 Ọmọ enia, sọ fun Farao ọba Egipti,
ati fun ọ̀pọlọpọ enia rẹ̀ pe, Tani iwọ jọ ni
titobi rẹ?
3 Kiyesi i, awọn ara Assiria ni igi kedari
ni Lebanoni ti o li ẹ̀ka daradara, ti o si ṣiji
boni, ti o si ga, ṣonṣo ori rẹ̀ si wà lãrin
awọn ẹ̀ka bibò.
4 Omi sọ ọ di nla, ibú gbé e ga soke, o fi
awọn odò nla rẹ̀ yi oko rẹ̀ ka, o si rán awọn
odo kékèké rẹ̀ si gbogbo igbẹ́.
5 Nitorina a gbe giga rẹ̀ soke jù gbogbo
igi igbẹ́ lọ, ẹ̀ka rẹ̀ si di pupọ̀, awọn ẹ̀ka rẹ̀
si di gigùn nitori ọ̀pọlọpọ omi, nigbati o yọ
wọn jade.
6 Gbogbo ẹiyẹ oju ọrun kọ́ itẹ́ wọn ninu
ẹ̀ka rẹ̀, ati labẹ ẹ̀ka rẹ̀ ni gbogbo ẹranko
igbẹ́ bi ọmọ wọn si, ati labẹ ojiji rẹ̀ ni
gbogbo awọn orilẹ-ède nla ngbe.
7 Bayi li o ni ẹwà ninu titobi rẹ̀, ninu
gigùn ẹ̀ka rẹ̀: nitoriti ti egbò rẹ̀ wà li ẹbá
omi nla.
8 Awọn igi kedari inu ọgbà Ọlọrun kò
le bò o mọlẹ: awọn igi firi kò dabi ẹ̀ka rẹ̀,
awọn igi kẹsnuti kò si dabi ẹ̀ka rẹ̀; bẽni
kò si igikigi ninu ọgbà Ọlọrun ti o dabi rẹ̀
li ẹwà rẹ̀.
9 Emi ti ṣe e li ẹwà nipa ọ̀pọlọpọ ẹ̀ka rẹ̀:
tobẽ ti gbogbo igi Edeni, ti o wà ninu ọgbà
Ọlọrun, ṣe ilara rẹ̀.
10 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Nitori ti on gbe ara rẹ̀ soke ni giga, o si
ti yọ ṣonṣo rẹ̀ soke lãrin awọn ẹ̀ka didí,
ọkàn rẹ̀ si gbe soke nitori giga rẹ̀;
11 Nitorina li emi ti ṣe fi i le alagbara
awọn keferi lọwọ; on o bá a ṣe dajudaju:
Emi ti lé e jade nitori buburu rẹ̀.
12 Ati awọn alejo, ẹlẹ́rù awọn orilẹ-ède,
ti ké e kuro, nwọn si ti tú u ká: ẹka rẹ̀
ṣubu sori awọn oke, ati ninu gbogbo afoni-
foji, ẹka rẹ̀ si ṣẹ́ lẹba gbogbo odò ilẹ na;
gbogbo awọn orilẹ-ède aiye si jade lọ kuro
labẹ ọ̀jiji rẹ̀, nwọn si fi i silẹ.
13 Gbogbo awọn ẹiyẹ oju ọrun yio ma
gbe ori ahoro rẹ̀, ati lori ẹ̀ka rẹ̀ ni gbogbo
ẹranko igbẹ́ yio wà.
14 Nitori ki igikigi ti o wà lẹba omi ki
o má ba gbe ara wọn ga nitori giga wọn,
tabi ki nwọn yọ ṣonṣo wọn lãrin ẹ̀ka dídi;
tabi ki igi wọn duro ni giga wọn, gbogbo
awọn ti o mu omi: nitori ti a fi gbogbo
wọn le ikú lọwọ, si isalẹ aiye, li ãrin awọn
ọmọ enia, pẹlu awọn ti o sọkalẹ lọ si ihò.
15 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; pe, Li ọjọ
ti o sọkalẹ lọ si iboji mo jẹ ki ọ̀fọ ki o wà,
mo fi ibú bò o mọlẹ, mo si se awọn iṣàn
omi, awọn omi nla ni mọ si dá duro: emi
si jẹ ki Lebanoni ki o ṣọ̀fọ fun u, gbogbo
igi igbẹ́ si dakú nitori rẹ̀.
16 Emi mu awọn orilẹ-ède mì nipa iró
iṣubu rẹ̀, nigbati mo sọ ọ sinu ipò-okú,
pẹlu awọn ti o sọkalẹ sinu ihò, ati gbogbo
igi Edeni, awọn àṣayan ati awọn ti o dara
jù ti Lebanoni, gbogbo awọn ti o mu omi,
li a o tù ninu ni isalẹ aiye.
17 Awọn pẹlu sọkalẹ lọ sinu ipò-okú
pẹlu rẹ̀ sọdọ awọn ti a fi idà pa; awọn ti o
si jẹ apá rẹ̀, ti ngbe abẹ ọ̀jiji rẹ̀ li ãrin awọn
keferi.
18 Tani iwọ jọ li ogo ati ni titobi lãrin
awọn igi Edeni? sibẹ a o mu ọ wá ilẹ pẹlu
awọn igi Edeni si isalẹ aiye, iwọ o dubulẹ
li ãrin awọn alaikọlà, pẹlu awọn ti a fi idà
pa. Eyi ni Farao ati gbogbo ọ̀pọlọpọ enia
rẹ̀, li Oluwa Ọlọrun wi.

## ORI 32.

OSI ṣe li ọdun kejila, li oṣù kejila, li ọjọ
ikini oṣù, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, pohunrére fun Farao ọba
Egipti, si wi fun u pe, Iwọ dabi ẹgbọ̀rọ
kiniun awọn orilẹ-ède, iwọ si dabi dragoni
ninu okun, iwọ si jade wá pẹlu awọn odò
rẹ, iwọ ti fi ẹsẹ rẹ rú omi, o si ti bà awọn
odò wọn jẹ́.
3 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Nitorina
emi o nà àwọn mi sori rẹ pẹlu ẹgbẹ́ enia
pupọ̀; nwọn o si fà ọ goke ninu àwọn mi.
4 Nigbana ni emi o fi ọ silẹ lori ilẹ, emi
o gbe ọ sọ sinu igbẹ́, emi o mu ki gbogbo
awọn ẹiyẹ oju ọrun ba le ọ lori, emi o si fi
ọ bọ́ gbogbo awọn ẹranko aiye.
5 Emi o gbe ẹran ara rẹ kà awọn ori oke,
gbogbo afonifoji li emi o fi giga rẹ kún.
6 Emi o si fi ẹ̀jẹ rẹ rin ilẹ nibiti iwọ
nluwẹ́, ani si awọn oke; awọn odò yio si
kún fun ọ.
7 Nigbati emi o ba mú ọ kuro, emi o bò
ọrun, emi o si mu ki awọn irawọ inu rẹ̀
ṣokùnkun, emi o fi kũkũ bò õrùn, ọ̀ṣupa ki
yio si fi imọlẹ rẹ̀ hàn.
8 Gbogbo imọlẹ oju ọrun li emi o mu

Digitized by Google

şokùnkun lori rẹ, emi o gbe okùnkun kà
ilẹ rẹ, li Oluwa Ọlọrun wi.
9 Emi o si bí ọ̀pọlọpọ enia ninu, nigbati
emi o ba mu iparun rẹ wá sãrin awọn orilẹ-
ède, si ilẹ ti iwọ kò ti mọ̀ ri.
10 Nitõtọ, emi o mu ki ẹnu yà ọ̀pọlọpọ
orilẹ-ède si ọ, awọn ọba wọn yio si bẹ̀ru
gidigidi nitori rẹ, nigbati emi o ba mì idà
mi niwaju wọn; nwọn o si warìri nigba-
gbogbo, olukuluku enia fun ẹmi ara rẹ̀, li
ọjọ iṣubu rẹ.
11 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Idà ọba Babiloni yio wá sori rẹ.
12 Emi o mu ki ọ̀pọlọpọ enia rẹ ṣubu
nipa idà awọn alagbara, ẹlẹ́rù awọn orilẹ-
ède ni gbogbo wọn; nwọn o si bà afẹ́
Egipti jẹ́, ati gbogbo ọ̀pọlọpọ enia rẹ̀ ni
nwọn o parun.
13 Emi o si pa gbogbo awọn ẹranko inu
rẹ̀ run kuro lẹba awọn omi nla, bẹ̃ni ẹsẹ
enia kì yio rú wọn mọ́ lailai, tabi pátakò
awọn ẹranko kì yio rú wọn.
14 Nigbana li emi o mu ki omi wọn ki o
rọlẹ, emi o si mu ki odò wọn ki o ṣàn bi
oróro, li Oluwa Ọlọrun wi.
15 Nigbati emi o mu ki ilẹ Egipti di
ahoro ti ilẹ na yio si di alaini ohun ti o
kún inu rẹ̀ ri, nigbati emi o kọlù gbogbo
awọn ti ngbe inu rẹ̀, nigbana ni nwọn o mọ̀
pe emi li Oluwa.
16 Eyi ni ohùn-rére, nwọn o si pohùn-
rére rẹ̀: awọn ọmọbirin awọn orilẹ-ède yio
pohùnrére rẹ̀: nwọn o pohùnrére nitori rẹ̀,
ani fun Egipti, ati gbogbo ọ̀pọlọpọ enia rẹ̀,
li Oluwa Ọlọrun wi.
17 O si tun ṣe li ọdun kejila, li ọjọ kẹ̃-
dogun oṣù, ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá, wipe.
18 Ọmọ enia, pohùnrére fun ọ̀pọlọpọ
enia Egipti ki o si sọ̀ wọn kalẹ̀, on, ati
awọn ọmọbirin orilẹ-ède olokiki, si ìsalẹ
aiye, pẹlu awọn ti o sọkalẹ lọ sinu ihò.
19 Tani iwọ julọ li ẹwà? sọkalẹ, ki a si
tẹ́ ọ tì awọn alaikọla.
20 Nwọn o ṣubu li ãrin awọn ti a fi idà
pa: a fi on le idà lọwọ: fà a, ati awọn
ọ̀pọlọpọ enia rẹ̀.
21 Awọn alagbara lãrin awọn alagbara
yio sọ̀rọ si i lati ãrin ipò-okú wá, pẹlu
awọn ti o ràn a lọwọ: nwọn sọkalẹ lọ,
nwọn dubulẹ, awọn alaikọla ti a fi idà
pa.
22 Assuru wà nibẹ̀ ati gbogbo ẹgbẹ́ rẹ̀:
awọn iboji rẹ̀ wà lọdọ rẹ̀: gbogbo wọn li a
pa, ti o ti ipa idà ṣubu:
23 Iboji awọn ẹniti a gbe kà ẹgbẹ́ ihò,
awọn ẹgbẹ́ rẹ̀ si yi iboji rẹ̀ ka, gbogbo wọn
li a pa, nwọn ti ipa idà ṣubu, ti o da ẹ̀ru
silẹ ni ilẹ alãye.
24 Elamu wà nibẹ, ati gbogbo ọ̀pọlọpọ
enia rẹ̀ yi iboji rẹ̀ ka, gbogbo wọn li a pa,
nwọn ti ipa idà ṣubu, ti nwọn sọkalẹ li
alaikọla si ìsalẹ aiye, ti o da ẹ̀ru wọn silẹ ni
ilẹ alãyè; sibẹ awọn ti rù itiju wọn pẹlu
awọn ti o sọkale lọ si ihò.
25 Nwọn ti gbe akete kan kalẹ fun u li
ãrin awọn ti a pa pẹlu gbogbo ọ̀pọlọpọ enia
rẹ̀: awọn iboji rẹ̀ yi i ka, gbogbo wọn alai-
kọla ti a fi idà pa: bi a tilẹ dá ẹ̀ru wọn
silẹ ni ilẹ alãye, sibẹ nwọn ti rù itiju wọn
pẹlu awọn ti o sọkalẹ lọ si ihò: a fi i si
ãrin awọn ti a pa.
26 Meşeki ati Tubali wà nibẹ, ati gbo-
gbo ọ̀pọlọpọ enia rẹ̀: awọn iboji rẹ̀ yi i ka:
gbogbo wọn alaikọlá ti a fi idà pa, bi nwọn
tilẹ dá ẹ̀ru wọn silẹ ni ilẹ alãye.
27 Nwọn kì yio si dubulẹ tì awọn ala-
gbara ti o ṣubu ninu awọn alaikọlà, ti nwọn
sọkalẹ lọ si ipò-okú pẹlu ihámọra ogun wọn:
nwọn ti fi idà wọn rọ ori wọn, ṣugbọn aiṣe-
dẽde wọn yio wà lori egungun wọn, bi nwọn
tilẹ jẹ ẹ̀ru awọn alagbara ni ilẹ alãye.
28 Lõtọ, a o fọ́ ọ lãrin awọn alaikọlà,
iwọ o si dubulẹ tì awọn ti a fi idà pa.
29 Edomu wà nibẹ, awọn ọba rẹ̀, ati
awọn ọmọ-alade rẹ̀, ti a tẹ́ pẹlu agbara wọn
tì awọn ti a fi idà pa, nwọn o dubulẹ tì
awọn alaikọlà, ati pẹlu awọn ti o sọkalẹ lọ
si ihò.
30 Awọn ọmọ-alade ariwa wà nibẹ, gbo-
gbo wọn, ati awọn ara Sidoni, ti nwọn
sọkalẹ lọ pẹlu awọn ti a pa; pẹlu ẹ̀ru wọn,
oju agbara wọn tì wọn; nwọn si dubulẹ li
alaikọlà pẹlu awọn ti a fi idà pa, nwọn si
rù itiju wọn pẹlu awọn ti o sọkalẹ lọ si ihò.
31 Farao yio ri wọn, a o si tù u ninu
lori gbogbo ọ̀pọlọpọ enia rẹ̀, ani Farao ati
gbogbo ogun rẹ̀ ti a fi idà pa, li Oluwa
Ọlọrun wi.
32 Nitoriti emi ti dá ẹ̀ru mi silẹ ni ilẹ
alãye: a o si tẹ́ ẹ si ãrin awọn alaikọlà,
pẹlu awọn ti a fi idà pa, ani Farao ati gbo-
gbo ọ̀pọlọpọ enia rẹ̀, li Oluwa Ọlọrun wi.

## ORI 33.

Ọ̀RỌ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, sọ fun awọn ọmọ enia rẹ,
si wi fun wọn pe, Bi emi bá mu idà wá
sori ilẹ kan, bi awọn enia ilẹ na bá mu
ọkọnrin kan ninu ara wọn, ti nwọn si fi ṣe
oluṣọ́ wọn:
3 Bi on bá ri ti idà mbọ̀ wá sori ilẹ na

Digitized by Google

ti o bá fun ipè, ti o si kìlọ fun awọn enia
na:
4 Nigbana ẹnikẹni ti o bá gbọ́ iró ipè, ti
kò si gbà ìkilọ; bi idà ba de, ti o si mu on
kuro, ẹjẹ rẹ̀ yio wà lori on tikalarẹ̀.
5 O gbọ́ iró ipè, kò si gbà ìkilọ: ẹ̀jẹ rẹ̀
yio wà lori rẹ̀. Ṣugbọn ẹniti o gbọ́ ìkilọ
yio gbà ọkàn ara rẹ̀ lá.
6 Ṣugbọn bi oluṣọ́ na bá ri ti idà mbọ̀, ti
kò si fun ipè, ti a kò si kìlọ fun awọn enia;
bi idà ba de, ti o ba si mu ẹnikẹni lãrin
wọn, a mu u kuro nitori aiṣedẽde rẹ̀, ṣu-
gbọn ẹjẹ rẹ̀ li emi o bere lọwọ oluṣọ́ na.
7 Bẹ̃ni, iwọ ọmọ enia, emi ti fi ọ ṣe
oluṣọ́ fun ile Israeli; nitorina iwọ o gbọ́
ọ̀rọ li ẹnu mi, iwọ o si kìlọ fun wọn lati
ọdọ mi.
8 Nigbati emi ba wi fun enia buburu pe,
Iwọ enia buburu, kikú ni iwọ o kú, bi iwọ
kò bá sọ̀rọ lati kìlọ fun enia buburu na ki
o kuro li ọ̀na rẹ̀, enia buburu na yio kú
nitori aiṣedẽde rẹ̀, ṣugbọn ẹjẹ rẹ̀ li emi o
bere li ọwọ́ rẹ.
9 Ṣugbọn, bi iwọ ba kìlọ fun enia bu-
buru na niti ọ̀na rẹ̀ lati pada kuro ninu rẹ̀,
bi on kò ba yipada kuro ninu ọ̀na rẹ̀, on o
kú nitori aiṣedẽde rẹ̀, ṣugbọn iwọ ti gbà
ọkàn rẹ là.
10 Nitorina, iwọ ọmọ enia, sọ fun ile
Israeli; pe, Bayi li ẹnyin nwi, pe, Bi ire-
kọja ati ẹ̀ṣẹ wa ba wà lori wa, ti awa si
njoró ninu wọn, bawo li a o ti ṣe le wà
lãye.
11 Sọ fun wọn pe, Bi emi ti wà, ni
Oluwa Ọlọrun wi, emi kò ni inu-didun ni
ikú enia buburu, ṣugbọn ki enia buburu
yipada kuro ninu ọ̀na rẹ̀ ki o si yè: ẹ
yipada, ẹ yipada kuro ninu ọ̀na buburu
nyin; nitori kini ẹnyin o ṣe kú, Ile Israeli?
12 Nitorina, iwọ ọmọ enia, sọ fun awọn
ọmọ enia rẹ, ododo olododo kì yio gbà a là
li ọjọ irekọja rẹ̀: bi o ṣe ti ìwa buburu
enia buburu, on kì yio ti ipa rẹ̀ ṣubu li ọjọ
ti o yipada kuro ninu ìwa buburu rẹ̀: bẹ̃ni
olododo kì yio là nipa ododo rẹ̀ li ọjọ ti o
dẹṣẹ.
13 Nigbati emi o wi fun olododo pe,
yiyè ni yio yè, bi o ba gbẹkẹle ododo ara rẹ̀,
ti o si ṣe aiṣedẽde, gbogbo ododo rẹ̀ li a kì
yio ranti mọ, ṣugbọn nitori aiṣedẽde ti o ti
ṣe, on o ti itori rẹ̀ kú.
14 Ẹwẹ, nigbati emi wi fun enia buburu
pe, Kikú ni iwọ o kú; bi on ba yipada ku-
ro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ti o si ṣe eyi ti o tọ ti o si
yẹ;
15 Bi enia buburu ba mu ògo padà, ti o
si san ohun ti o ti jí padà, ti o si nrin ni
ilana ìye, li aiṣe aiṣedẽde; yiyè ni yio yè,
on kì o kú.
16 A kì yio ṣe iranti gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o
ti ndá fun u: on ti ṣe eyi ti o tọ ti o si yẹ;
on o yè nitõtọ.
17 Sibẹ awọn ọmọ enia rẹ wipe, Ọ̀na
Oluwa kò dọgba; ṣugbọn bi o ṣe ti wọn ni,
ọ̀na wọn kò dọgba.
18 Nigbati olododo ba yipada kuro ninu
ododo rẹ̀ ti o si ṣe aiṣedẽde, on o ti ipa rẹ̀
kú.
19 Ṣugbọn bi enia buburu bá yipada
kuro ninu buburu rẹ̀, ti o si ṣe eyiti o tọ ti
o si yẹ, on o ti ipa rẹ̀ wà lãye.
20 Sibẹ ẹnyin wi pe, Ọ̀na Oluwa kò
dọgba, Ẹnyin ile Israeli, emi o dá olukulu-
ku nyin li ẹjọ gẹgẹ bi ọ̀na rẹ̀.
21 O si ṣe li ọdun ikejila ikolọ wa, li oṣu
kẹwa, li ọjọ karun oṣu, ẹnikan ti o ti salà
jade ni Jerusalemu tọ̀ mi wá, o wipe, A
kọlù ilu na.
22 Ọwọ́ Oluwa si wà lara mi li àṣalẹ, ki
ẹniti o salà na to de; o si ti ṣi ẹnu mi, titi
on fi wá sọdọ mi li owurọ; ẹnu mi si ṣi,
emi kò si yadi mọ.
23 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa tọ̀ mi wá,
wipe,
24 Ọmọ enia, awọn ti ngbe ahoro ile
Israeli wọnni sọ, wipe, Abrahamu jẹ ẹni-
kan, on si jogun ilẹ na: ṣugbọn awa pọ̀, a
fi ilẹ na fun wa ni ini.
25 Nitorina wi fun wọn pe, Bayi li Olu-
wa Ọlọrun wi, pe, ẹnyin njẹ ẹ̀jẹ mọ ẹran,
ẹ si gbe oju nyin soke si awọn oriṣa nyin,
ẹ si ta ẹjẹ silẹ, ẹnyin o ha ni ilẹ na?
26 Ẹnyin gbẹkẹle idà nyin, ẹ ṣe irira,
olukuluku nyin bà obirin aladugbò rẹ̀ jẹ́:
ẹnyin o ha ni ilẹ na?
27 Iwọ wi bayi fun wọn pe, Bayi li Olu-
wa Ọlọrun wi; Bi emi ti wà, nitõtọ, awọn
ti o wà ninu ahoro na yio ti ipa idà ṣubu,
ẹniti o si wà ni gbangba oko li emi o si fi
fun ẹranko lati pajẹ, awọn ti o si wà ninu
odi ati ninu ihò okuta yio ti ipa ajakalẹ-
àrun kú.
28 Nitoriti emi o sọ ilẹ na di ahoro pata-
pata, ọ̀ṣọ nla agbara rẹ̀ kì yio si mọ, awọn
oke Israeli yio si di ahoro, ti ẹnikan kì yio
le là a kọja.
29 Nigbana ni nwọn o mọ̀ pe emi li Olu-
wa, nigbati mo ba ti sọ ilẹ na di ahoro
patapata, nitori gbogbo irira ti nwọn ti ṣe.
30 Iwọ ọmọ enia, sibẹ awọn ọmọ enia rẹ
nsọ̀rọ si ọ lẹba ogiri ati lẹba ìlẹkun ile, ẹni-
kini si sọ fun ẹnikeji, olukuluku fun ara-

Digitized by Google

kọnrin rẹ̀ wipe, Wá, emi bẹ̀ ọ si gbọ́ ọ̀rọ ti
o ti ọdọ Oluwa jade wá.
31 Nwọn si tọ̀ ọ wá, bi enia ti iwá,
nwọn si joko niwaju rẹ bi enia mi, nwọn si
gbọ́ ọ̀rọ rẹ, ṣugbọn nwọn kì yio ṣe wọn:
nitori ẹnu wọn ni nwọn fi nfi ifẹ pupọ hàn,
ṣugbọn ọkàn wọn tẹ̀le ojukokoro wọn.
32 Si kiyesi i, iwọ jẹ orin ti o dùn pupọ
fun wọn, ti ẹnikan ti o ni ohùn daradara,
ti o si le fún ohun-elò orin daradara: nito-
ri nwọn gbọ́ ọ̀rọ rẹ, ṣugbọn nwọn kò ṣe
wọn.
33 Ati nigbati eyi bá ṣẹ, (kiyesi i, yio
de,) nigbana ni nwọn o mọ̀ pe wolĩ kan ti
wà lãrin wọn.

## ORI 34.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, sọtẹlẹ si awọn oluṣọ́ agu-
tan Israeli, sọtẹlẹ, ki o si wi fun wọn pe,
Bayi li Oluwa Ọlọrun wi fun awọn oluṣọ́
agutan; pe, Egbé ni fun awọn oluṣọ agu-
tan Israeli, ti mbọ́ ara wọn, awọn oluṣọ́
agutan kì ba bọ́ ọwọ́-ẹran?
3 Ẹnyin jẹ ọrá, ẹ si fi irun agutan bora,
ẹ pa awọn ti o sanra: ẹ kò bọ́ agbo-ẹran.
4 Ẹnyin kò mu alailera lara le, bẹ̃ni ẹ
kò mu eyiti kò sàn li ara da, bẹ̃ni ẹ kò dì
eyiti a ṣá lọ́gbẹ, bẹ̃ni ẹ kò tun mu eyi ti a
ti lé lọ padà bọ̀, bẹ̃ni ẹ kò wá eyiti o sọnu,
ṣugbọn ipá ati ìka li ẹ ti fi nṣe akoso wọn.
5 A si tú wọn ka, nitori ti oluṣọ́ agutan
kò si: nwọn si di onjẹ fun gbogbo ẹranko
igbẹ́, nigbati a tú wọn ka.
6 Awọn agutàn mi ṣako ni gbogbo òke,
ati lori gbogbo òke kékèké, nitõtọ, a tú
ọwọ́-ẹran mi ká ilẹ gbogbo, ẹnikẹni kò bere
wọn ki o si wá wọn lọ.
7 Nitorina ẹnyin oluṣọ́ agutan, ẹ gbọ̀
ọ̀rọ Oluwa.
8 Bi mo ti wà, ni Oluwa Ọlọrun wi, ni-
tõtọ, nitori ti ọwọ́-ẹran mi di ijẹ, ti ọwọ́-
ẹran mi di onjẹ fun olukuluku ẹranko igbẹ́,
nitoriti kò si oluṣọ́ agutan, bẹ̃ni awọn olu-
ṣọ́ agutan kò wá ọwọ́-ẹran mi ri, ṣugbọn
awọn oluṣọ́ agutan bọ́ ara wọn, nwọn kò si
bọ́ ọwọ́-ẹran mi.
9 Nitorina, ẹnyin oluṣọ́ agutan, ẹ gbọ́
ọ̀rọ Oluwa;
10 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Kiyesi i,
emi dojukọ awọn oluṣọ́ agutan; emi o si
bere ọwọ́-ẹran mi lọwọ wọn, emi o si mu
wọn dẹ́kun ati ma bọ́ awọn ọwọ́-ẹran: bẹ̃ni
awọn oluṣọ́ agutan kì yio bọ́ ara wọn mọ,
nitori ti emi o gbà ọwọ́-ẹran mi kuro li ẹnu
wọn ki nwọn ki o má ba jẹ onjẹ fun wọn.
11 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Kiyesi i, emi, ani emi, o bere awọn agutan
mi, emi o si wá wọn ri.
12 Gẹgẹ bi oluṣọ́ agutan iti iwá ọwọ́-ẹran
rẹ̀ ri, li ọjọ ti o wà lãrin awọn agutan rẹ̀ ti
o fọnka, bẹ̃li emi o wá agutan mi ri, emi o
si gbà wọn nibi gbogbo ti wọn ti fọnka si,
li ọjọ kũkũ ati okùnkun biribiri.
13 Emi o si mu wọn jade kuro ninu awọn
orilẹ ède, emi o si kó wọn jọ lati ilẹ gbo-
gbo, emi o si mu wọn wá si ilẹ ara wọn,
emi o si bọ́ wọn lori oke Israeli, lẹba odò,
ati ni ibi gbigbé ni ilẹ na.
14 Emi o bọ́ wọn ni pápa oko daradara
ati lori okè giga Israeli ni agbo wọn o wà:
nibẹ ni nwọn o dubulẹ ni agbo daradara,
pápa oko ọlọ́ra ni nwọn o si ma jẹ lori oke
Israeli.
15 Emi o bọ́ ọwọ́-ẹran mi, emi o si mu
ki nwọn dubulẹ, li Oluwa Ọlọrun wi.
16 Emi o wá eyiti o sọnu lọ, emi o si
mu eyiti a lé lọ pada bọ̀, emi o si dì eyiti a
ṣá lọ́gbẹ, emi o mu eyiti o ṣaisan li ara le;
ṣugbọn emi o run eyiti o sanra ati eyiti o
lagbara; emi o fi idajọ bọ́ wọn.
17 Bi o ṣe ti nyin, Ẹnyin ọwọ́-ẹran mi,
bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Kiyesi i, emi o
ṣe idajọ lãrin ẹran ati ẹran, lãrin àgbo ati
abukọ.
18 Ohun kekere ni li oju nyin ti ẹ ti jẹ
oko daradara, ṣugbọn ẹnyin si fi ẹsẹ tẹ oko
iyokù mọlẹ, ati ti ẹ ti mu ninu omi jíjìn,
ṣugbọn ẹ si fi ẹsẹ ba eyi ti o kù jẹ?
19 Bi o ṣe ti ọwọ́-ẹran mi ni, nwọn jẹ
eyiti ẹ ti fi ẹsẹ nyin tẹ̀ mọlẹ; nwọn si mu
eyiti ẹ ti fi ẹsẹ nyin bajẹ.
20 Nitorina, bayi li Oluwa Ọlọrun wi
fun wọn, Kiyesi, emi, ani emi, o ṣe idajọ
lãrin ọwọ́-ẹran ti o sanra, ati eyiti o rù.
21 Nitoriti ẹnyin ti fi ẹgbẹ́ ati ejiká
gbún, ti ẹ si ti fi iwo nyin kàn gbogbo
awọn ti o li àrun titi ẹ fi tú wọn kakiri.
22 Nitorina ni emi o ṣe gbà ọwọ́-ẹran mi
là, nwọn kì yio si jẹ ijẹ́ mọ, emi o si ṣe
idajọ lãrin ẹran ati ẹran.
23 Emi o si gbe oluṣọ́ agutan kan soke
lori wọn, on o si bọ́ wọn, ani Dafidi iranṣẹ
mi; on o bọ́ wọn, on o si jẹ oluṣọ́ agutan
wọn.
24 Emi Oluwa yio si jẹ Ọlọrun wọn, ati
Dafidi iranṣẹ mi o jẹ ọmọ-alade li ãrin wọn,
emi Oluwa li o ti sọ ọ.
25 Emi o si ba wọn da majẹmu alafia,
emi o si jẹ ki awọn ẹranko buburu dasẹ̀ ni
ilẹ na: nwọn o si ma gbe aginju li ailewu,
nwọn o si sùn ninu igbó.

Digitized by Google

26 Emi o si ṣe awọn ati ibi ti o yi oke mi ká ni ibukún; emi o si jẹ ki òjo ki o rọ̀ li akoko rẹ̀, òjo ibukún yio wà.

27 Igi igbẹ́ yio si so eso rẹ̀, ilẹ yio si ma mu asunkun rẹ̀ wá, nwọn o si wà li alafia ni ilẹ wọn, nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa, nigbati emi o ti ṣẹ́ èdídi àjaga wọn, ti emi o si ti gbà wọn lọwọ awọn ti nwọn nsìn bi ẹrú.

28 Nwọn kì yio si ṣe ijẹ fun awọn keferi mọ, bẽni ẹranko ilẹ na kì yio pa wọn jẹ, ṣugbọn nwọn o wà li alafia ẹnikẹni kì yio si dẹrùba wọn,

29 Emi o si gbe igi okiki kan soke fun wọn, ebi kì yio si run wọn ni ilẹ na mọ, bẽni nwọn kì yio rù itiju awọn keferi mọ.

30 Bayi ni nwọn o mọ̀ pe emi Oluwa Ọlọrun wọn wà pẹlu wọn, ati awọn, ile Israeli, jẹ enia mi, li Oluwa Ọlọrun wi.

31 Ati ẹnyin ọwọ́-ẹran mi, ọwọ́-ẹran pápa oko mi ni enia, emi si li Ọlọrun nyin, li Oluwa Ọlọrun wi.

## ORI 35.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
2 Ọmọ enia, kọ oju rẹ si oke Seiri, ki o si sọtẹlẹ si i.
3 Ki o si wi fun u pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, Kiyesi i, iwọ oke Seiri, emi dojukọ ọ, emi o nà ọwọ́ mi si ọ, emi o si sọ ọ di ahoro patapata.
4 Emi o sọ awọn ilu rẹ di ahoro, iwọ o si di ahoro, iwọ o si mọ̀ pe, emi li Oluwa.
5 Nitori ti iwọ ti ni irira lailai, iwọ si ti fi awọn ọmọ Israeli le idà lọwọ́, li akoko ìjàmu wọn, li akoko ti aiṣedẽde wọn de opin.
6 Nitorina, bi emi ti wà, ni Oluwa Ọlọrun wi, emi o pèse rẹ silẹ fun ẹ̀jẹ, ẹ̀jẹ yio si lepa rẹ: bi iwọ kò ti korira ẹ̀jẹ ni, ẹ̀jẹ yio lepa rẹ.
7 Bayi li emi o sọ oke Seiri di ahoro patapata, emi o si ké ẹniti nkọja lọ ati ẹniti npadà bọ̀ kuro ninu rẹ̀.
8 Emi o si fi awọn okú rẹ̀ kún awọn oke rẹ̀; ni oke kékèké rẹ, ati ni afonifoji rẹ, ati ni gbogbo odò rẹ li awọn ti a fi idà pa yio ṣubu si.
9 Emi o sọ ọ di ahoro lailai, awọn ilu rẹ kì yio si padà bọ̀: ẹnyin o si mọ̀ pe, emi li Oluwa.
10 Nitoriti iwọ ti wipe, Awọn orilẹ-ède mejeji yi, ati awọn ilẹ mejeji yi yio jẹ́ ti emi, awa o si ni i; nigbati o ṣepe Oluwa wà nibẹ:
11 Nitorina, bi emi ti wà, ni Oluwa Ọlọrun wi, emi o tilẹ ṣe gẹgẹ bi ibinu rẹ, ati gẹgẹ bi ilara rẹ ti iwọ ti lò lati inu irira rẹ si wọn; emi o si sọ ara mi di mimọ̀ lãrin wọn, nigbati emi ba ti da ọ li ẹjọ.
12 Iwọ o si mọ̀ pe emi li Oluwa, ati pe emi ti gbọ́ ọ̀rọ buburu rẹ, ti iwọ ti sọ si oke Israeli, wipe, A sọ wọn di ahoro, a fi wọn fun wa lati run.
13 Bayi li ẹnyin ti fi ẹnu nyin buná si mi, ẹ si ti sọ ọ̀rọ nyin di pupọ si mi: emi ti gbọ́.
14 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi pe, Nigbati gbogbo aiye nyọ̀, emi o sọ ọ di ahoro.
15 Gẹgẹ bi iwọ ti yọ̀ si ini ile Israeli, nitori ti o di ahoro, bẽli emi o ṣe si ọ; iwọ o di ahoro, iwọ oke Seiri ati gbogbo Idumea, ani gbogbo rẹ̀: nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.

## ORI 36.

ATI iwọ, ọmọ enia, sọtẹlẹ si awọn oke Israeli, si wipe, Ẹnyin oke Israeli, ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa:
2 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, Nitori ti ọta ti wi si nyin pe, Aha, ani ibi giga igbãni jẹ tiwa ni ini:
3 Nitorina sọtẹlẹ, ki o si wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, pe, Nitõtọ nitori nwọn ti sọ ọ di ahoro, ti nwọn si gbe ọ mì niha gbogbo, ki ẹnyin ba le jẹ ini fun awọn keferi iyokù, ti a mu nyin si ẹnu, ti ẹnyin si jasi ẹ̀gan awọn enia:
4 Nitorina, ẹnyin oke Israeli, ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa Ọlọrun; Bayi li Oluwa Ọlọrun wi fun awọn oke-nla, ati fun awọn oke kékèké, fun awọn odò, ati fun awọn afonifoji, fun ibi idahoro, ati fun awọn ilu ti a kọ̀ silẹ, ti o di ijẹ ati iyọṣùtisi fun awọn keferi iyokù ti o yika kiri;
5 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Nitõtọ ninu iná owu mi li emi ti sọ̀rọ si awọn keferi iyokù, ati si gbogbo Idumea, ti o ti fi ayọ̀ inu wọn gbogbo yàn ilẹ mi ni iní wọn, pẹlu àrankan inu, lati ta a nù fun ijẹ.
6 Nitorina sọtẹlẹ niti ilẹ Israeli, ki o si wi fun awọn oke nla, ati fun awọn oke kékèké, fun awọn odò, ati fun awọn afonifoji, pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, Wò o, emi ti sọ̀rọ ninu owu mi, ati ninu irúnu mi, nitori ti ẹnyin ti rù itiju awọn keferi.
7 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi; emi ti gbe ọwọ́ mi soke, Nitõtọ awọn keferi ti o yi nyin ka, awọn ni yio rù itiju wọn.
8 Ṣugbọn ẹnyin, oke Israeli, ẹnyin o yọ

Digitized by Google

ẹka jade, ẹ o si so eso nyin fun Israeli enia
mi; nitori nwọn fẹrẹ de.
9 Si kiyesi i, emi wà fun nyin, emi o si
yipadà si nyin, a o si ro nyin, a o si gbìn
nyin:
10 Emi o si mu enia bi si i lori nyin,
gbogbo ile Israeli, ani gbogbo rẹ̀: awọn ilu
yio si ni olugbe, a o si kọ́ ibi ti o di ahoro:
11 Emi o si mu enia ati ẹranko bi si i
lori nyin; nwọn o si pọ̀ si i, nwọn o si rẹ̀:
emi o si mu nyin joko ni ibugbe nyin, bi ti
atijọ, emi o si ṣe si nyin jù igbà ibẹrẹ nyin
lọ: ẹnyin o si mọ̀ pe, emi li Oluwa.
12 Nitõtọ, emi o mu ki enia rìn lori
nyin, ani Israeli enia mi; nwọn o si ni ọ,
iwọ o si jẹ iní wọn, iwọ kì yio si gbà wọn
li ọmọ mọ lati isisiyi lọ.
13 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Nitori
nwọn wi fun nyin, pe, Iwọ jẹ enia run, o si
ti gbà awọn orilẹ-ède li ọmọ;
14 Nitorina iwọ kì yio jẹ enia run mọ,
bẽni iwọ kì yio gbà awọn orilẹ rẹ li ọmọ
mọ, li Oluwa Ọlọrun wi.
15 Bẽni emi kì yio mu ki enia gbọ́ ìtiju
awọn keferi ninu rẹ mọ, bẽni iwọ kì yio rù
ẹ̀gan awọn orilẹ-ède mọ, bẽni iwọ kì yio mu
ki orilẹ-ẹ̀de re ṣubu mọ, li Oluwa Ọlọrun
wi.
16 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
17 Ọmọ enia, nigbati ile Israeli ngbe ilẹ
ti wọn; nwọn bà a jẹ nipa ọ̀na wọn, ati
nipa iṣe wọn: ọ̀na wọn loju mi dabi aimọ́
obirin ti a mu kuro.
18 Nitorina emi fi irúnu mi si ori wọn,
nitori ẹ̀jẹ ti wọn ti ta sori ilẹ na, ati nitori
ere wọn ti wọn ti fi bà a jẹ.
19 Emi si ti tú wọn ká sãrin awọn kefe-
ri, a si fọn wọn ká si gbogbo ilẹ: emi dá
wọn lẹjọ, gẹgẹ bi ọ̀na wọn, ati gẹgẹ bi iṣe
wọn.
20 Nigbati awọn si wọ̀ inu awọn keferi,
nibiti nwọn lọ, nwọn bà orukọ mimọ́ mi jẹ,
nigbati nwọn wi fun wọn pe, Awọn wọnyi
li enia Oluwa, nwọn si ti jade kuro ni ilẹ
rẹ̀.
21 Ṣugbọn ãnu orukọ mimọ́ mi ṣe mi, ti
ile Israeli ti bajẹ lãrin awọn keferi, nibiti
nwọn lọ.
22 Nitorina sọ fun ile Israeli, pe, Bayi
li Oluwa Ọlọrun wi; Ile Israeli, emi kò ṣe
eyi nitori ti nyin, ṣugbọn fun orukọ mimọ́
mi, ti ẹnyin ti bajẹ lãrin awọn keferi, ni-
biti ẹnyin lọ.
23 Emi o si sọ orukọ nla mi di mimọ́, ti
a bajẹ lãrin awọn keferi, ti ẹnyin ti bajẹ
lãrin wọn; awọn keferi yio si mọ̀ pe emi li
Oluwa, nigbati a o sọ mi di mimọ́ ninu
nyin niwaju wọn, li Oluwa Ọlọrun wi.
24 Nitori emi o mu nyin kuro lãrin awọn
keferi, emi o si ṣà nyin jọ kuro ni gbogbo
ilẹ, emi o si mu nyin padà si ilẹ ti nyin.
25 Nigbana ni emi o fi omi mimọ́ wọ́n
nyin, ẹnyin o si mọ́: emi o si wẹ̀ nyin mọ́
kuro ninu gbogbo ẹgbin nyin, ati kuro ninu
gbogbo oriṣa nyin.
26 Emi o fi ọkàn titun fun nyin pẹlu,
ẹmi titun li emi o fi sinu nyin, emi o si mu
ọkàn okuta kuro lara nyin, emi o si fi ọkàn
ẹran fun nyin.
27 Emi o si fi ẹmi mi sinu nyin, emi o
si mu ki ẹ ma rìn ninu aṣẹ mi, ẹnyin o pa
idajọ mi mọ, ẹ o si ma ṣe wọn.
28 Ẹnyin o si ma gbe ilẹ ti emi fi fun
awọn baba nyin; ẹnyin o si ma jẹ enia mi,
emi o si ma jẹ Ọlọrun nyin.
29 Emi o si gbà nyin là kuro ninu aimọ́
nyin gbogbo: emi o si pè ọkà wá, emi o si
mu u pọ̀ si i, emi kì yio si mu ìyan wá ba
nyin.
30 Emi o si sọ eso-igi di pupọ̀, ati ibísi
oko, ki ẹ má bà gbà ẹ̀gan ìyan mọ lãrin
awọn keferi.
31 Nigbana li ẹnyin o ranti ọ̀na buburu
nyin, ati iṣe nyin ti kò dara, ẹ o si sú ara
nyin li oju ara nyin fun aiṣedẽde nyin, ati
fun irira nyin.
32 Kì iṣe nitori ti nyin li emi ṣe eyi, ni
Oluwa Ọlọrun wi, ẹ mọ̀ eyi: ki oju ki o ti
nyin, ki ẹ si dãmú nitori ọ̀na ara nyin, ile
Israeli.
33 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Li ọjọ ti
emi o ti wẹ̀ nyin mọ́ kuro ninu aiṣedẽde
nyin gbogbo, emi o mu ki a tun gbe ilu, a
o si kọ́ ibi ahoro wọnni.
34 Ilẹ ahoro li a o si ro, ti o ti di ahoro
li oju gbogbo awọn ti o ti kọja.
35 Nwọn o si wipe, Ilẹ yi ti o ti di ahoro
ti dabi ọgbà Edeni; ati ilu ti o tú, ti o di
ahoro, ti o si parun, di ilu olodi, o si ni
olugbe.
36 Nigbana ni awọn keferi iyokù yika
nyin yio mọ̀ pe emi Oluwa ti kọ́ ilu ti o
parun, emi si ti gbìn eyiti o ti di ahoro:
emi Oluwa ti sọ ọ, emi o si ṣe e.
37 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Ile Israeli
yio bere eyi lọwọ mi, lati ṣe e fun wọn, emi
o mu enia bi si i fun wọn bi ọwọ́-ẹran.
38 Gẹgẹ bi ọwọ́-ẹran mimọ́, bi ọwọ́-ẹran
Jerusalemu ni àse wọn ti o ni ironu, bẽni
ilu ti o di ahoro yio kún fun enia: nwọn o
si mọ̀ pe, emi li Oluwa.

Digitized by Google

## ORI 37.

OWỌ Oluwa wà li ara mi, o si mu mi
jade ninu ẹmi Oluwa, o si gbe mi kalẹ
li ãrin afonifojì ti o kún fun egungun,
2 O si mu mi rìn yi wọn ka: si wò o,
ọ̀pọlọpọ ni mbẹ ni gbangba afonifoji: si
kiyesi i, nwọn gbẹ pupọpupọ.
3 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, egungun
wọnyi le yè? Emi si wipe, Oluwa Ọlọrun,
iwọ li o le mọ̀.
4 O tun wi fun mi pe, Sọtẹlẹ sori egun-
gun wọnyi, si wi fun wọn pe, Ẹnyin egun-
gun gbigbẹ, ẹ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa.
5 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi fun egungun
wọnyi; Kiyesi i, emi o mu ki ẽmi wọ̀ inu
nyin, ẹnyin o si yè:
6 Emi o si fi iṣan sara nyin, emi o si mu
ẹran wá sara nyin, emi o si fi àwọ bò nyin,
emi o si fi ẽmi sinu nyin, ẹnyin o si yè;
ẹnyin o si mọ̀ pe emi li Oluwa.
7 Bẹ̃ni mo ṣotẹlẹ gẹgẹ bi a ti paṣẹ fun
mi: bi mo si ti sọtẹlẹ, ariwo ta, si wò o,
mimì kan wà, awọn egungun na si wá ọdọ
ara wọn, egungun si egungun rẹ̀.
8 Nigbati mo si wò, kiyesi i, iṣan ati
ẹran-ara wá si wọn, àwọ si bò wọn loke:
ṣugbọn ẽmi kò si ninu wọn.
9 Nigbana li o sọ fun mi, pe, ọmọ enia,
Sọtẹlẹ si ẽmi, sọtẹlẹ, si wi fun ẽmi pe,
Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Iwọ ẽmi, wá lati
igun mẹrẹrin, si mí si okú wọnyi, ki nwọn
ba le yè.
10 Bẹ̃ni mo sọtẹlẹ gẹgẹ bi a ti paṣẹ fun
mi, ẽmi na si wá sinu wọn, nwọn si yè,
nwọn si dide duro li ẹsẹ wọn ogun nlanla.
11 Nigbana li o sọ fun mi pe, Ọmọ enia,
egungun wọnyi ni gbogbo ile Israeli: wò
o, nwọn wipe, Egungun wa gbẹ, ireti wa si
pin: ni ti awa, a ti ke wa kuro.
12 Nitorina sọtẹlẹ ki o si wi fun wọn pe,
Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Kiyesi i, ẹnyin
enia mi, emi o ṣi iboji nyin, emi o si mu
ki ẹ dide kuro ninu iboji nyin, emi o si mu
nyin wá si ilẹ Israeli.
13 Ẹnyin o si mọ̀ pe emi li Oluwa, nigba-
ti emi bá ti ṣí iboji nyin, ẹnyin enia mi, ti
emi bá si mu nyin dide kuro ninu iboji
nyin.
14 Emi o si fi ẹmi mi sinu nyin, ẹnyin o
si yè, emi o si mu nyin joko ni ilẹ ti nyin:
nigbana li ẹnyin o mọ̀ pe, emi Oluwa li o
ti sọ ọ, ti o si ti ṣe e, li Oluwa wi.
15 Ọ̀rọ Oluwa tun tọ̀ mi wá, wipe,
16 Ati iwọ, ọmọ enia, mu igi kan, si
kọwe si i lara, Fun Juda, ati fun awọn ọmọ
Israeli ẹgbẹ́ rẹ̀: si mu igi miran, si kọwe ṣi
i lara, Fun Josefu, igi Efraimu, ati fun
gbogbo ile Israeli ẹgbẹ́ rẹ̀.
17 Si dà wọn pọ̀ ṣọkan si igi kan; nwọn
o si di ọkan li ọwọ́ rẹ.
18 Nigbati awọn enia rẹ ba ba ọ sọ̀rọ,
wipe, Iwọ kì yio fi idi nkan wọnyi hàn wa?
19 Wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun
wi; Kiyesi i, emi o mu igi Josefu, ti o wà
li ọwọ́ Efraimu, ati awọn ẹya Israeli ẹgbẹ́
rẹ̀, emi o si mu wọn pẹlu rẹ̀, pẹlu igi Juda,
emi o si sọ wọn di igi kan, nwọn o si di
ọkan li ọwọ́ mi.
20 Igi ti iwọ kọwe si lara yio wà li ọwọ́
rẹ, niwaju wọn.
21 Si wi fun wọn pe, Bayi li Oluwa
Ọlọrun wi; Kiyesi i, emi o mu awọn ọmọ
Israeli kuro lãrin awọn keferi, nibiti nwọn
lọ, emi o si ṣà wọn jọ niha gbogbo, emi o
si mu wọn wá si ilẹ ti wọn.
22 Emi o si sọ wọn di orilẹ-ède kan ni
ilẹ lori oke-nla Israeli; ọba kan ni yio si jẹ
lori gbogbo wọn: nwọn kì yio si jẹ orilẹ-
ède meji mọ, bẹ̃ni a kì yio sọ wọn di ijọba
meji mọ rara.
23 Bẹ̃ni nwọn kì yio fi oriṣa wọn bà ara
wọn jẹ mọ, tabi ohun-irira wọn, tabi ohun
irekọja wọn: ṣugbọn emi o gbà wọn là
kuro ninu gbogbo ibugbe wọn, nibiti nwọn
ti dẹṣẹ, emi o si wẹ̀ wọn mọ́: bẹ̃ni nwọn o
jẹ enia mi, emi o si jẹ Ọlọrun wọn.
24 Dafidi iranṣẹ mi yio si jẹ ọba lori
wọn; gbogbo wọn ni yio si ni oluṣọ-agu-
tan kan: nwọn o rìn ninu idajọ mi pẹlu,
nwọn o si kiyesi aṣẹ mi, nwọn o si ṣe wọn.
25 Nwọn o si ma gbe ilẹ ti emi ti fi fun
Jakobu iranṣẹ mi, nibiti awọn baba nyin
ti gbe; nwọn o si ma gbe inu rẹ̀, awọn,
ati awọn ọmọ wọn, ati awọn ọmọ ọmọ wọn
lailai: Dafidi iranṣẹ mi yio si ma jẹ ọmọ-
alade wọn lailai.
26 Pẹlupẹlu emi o ba wọn dá majẹmu
alafia; yio si jẹ majẹmu aiyeraiye pẹlu
wọn: emi o si gbe wọn kalẹ, emi o si mu
wọn rẹ̀, emi o si gbe ibi mimọ́ mi si ãrin
wọn titi aiye.
27 Agọ mi yio wà pẹlu wọn: nitõtọ, emi
o si jẹ Ọlọrun wọn, nwọn o si jẹ enia mi.
28 Awọn keferi yio si mọ̀ pe, emi Oluwa
li o ti sọ Israeli di mimọ́, nigbati ibi mimọ́
mi yio wà li ãrin wọn titi aiye.

## ORI 38.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ mi wá wipe,
2 Ọmọ enia, kọ oju rẹ si Gogu, ilẹ

Digitized by Google

Magogu, olori Roṣi, Meṣeki, ati Tubali, si sọtẹlẹ si i,

3 Si wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Kiyesi i, emi dojukọ ọ, iwọ Gogu, olori Roṣi, Meṣeki, ati Tubali:

4 Emi o si dá ọ padà, emi o si fi ìwọ kọ́ ọ li ẹ̀rẹkẹ́, emi o si mu ọ jade wá, ati gbogbo ogun rẹ, ẹṣin ati ẹlẹṣin, gbogbo wọn li a wọ̀ laṣọ daradara, ani ẹgbẹ́ nla pẹlu apata on asà, gbogbo wọn dì idà mu:

5 Persia, Etiopia, ati Libia pẹlu wọn; gbogbo wọn pẹlu asà on akoro:

6 Gomeri, ati gbogbo ogun rẹ̀; ile Togarma ti ihà ariwa, ati gbogbo ogun rẹ̀: enia pupọ̀ pẹlu rẹ̀.

7 Iwọ mura silẹ, si mura fun ara rẹ, iwọ, ati gbogbo ẹgbẹ́ rẹ ti a gbajọ fun ọ, ki iwọ jẹ alãbo fun wọn.

8 Lẹhìn ọjọ pupọ̀ li a o bẹ̀ ọ wò: li ọdun ikẹhìn, iwọ o wá si ilẹ ti a gbà padà lọwọ idà, ti a si kojọ pọ̀ kuro lọdọ enia pupọ̀, lori oke-nla Israeli, ti iti ma di ahoro: ṣugbọn a mu u jade kuro ninu awọn orilẹ-ède, nwọn o si ma gbe li ailewu, gbogbo wọn.

9 Iwọ o goke wá, iwọ o si de bi ijì, iwọ o dabi awọsanma lati bò ilẹ, iwọ, ati gbogbo awọn ogun rẹ, ati ọ̀pọlọpọ enia pẹlu rẹ.

10 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; yio si ṣe pe nigbakanna ni nkan yio sọ si ọkàn rẹ, iwọ o si rò èro ibi kan.

11 Iwọ o si wipe, emi o goke lọ si ilẹ ileto ti kò ni odi: emi o tọ̀ awọn ti o wà ni isimi lọ, ti nwọn ngbe laibẹ̀ru, ti gbogbo wọn ngbe laisi odi, ti nwọn kò si ni agbaràirin tabi ẹnu-odi,

12 Lati lọ kó ikogun, ati lati lọ mu ohun ọdẹ; lati yi ọwọ́ rẹ si ibi ahoro wọnni ti a tẹ̀do nisisiyi, ati si enia ti a kojọ lati inu awọn orilẹ-ède wá, awọn ti o ti ni ohun-ọ̀sin ati ẹrù, ti ngbe oke ilẹ na.

13 Ṣeba ati Dedani, ati awọn oniṣòwo Tarṣiṣi, pẹlu gbogbo awọn ọmọ kiniun wọn, yio si wi fun ọ pe, Ikogun ni iwọ wá kó? lati wá mu ohun ọdẹ li o ṣe gbá awọn ẹgbẹ́ rẹ jọ? lati wá rù fadaka ati wura lọ, lati wá rù ohun-ọsìn ati ẹrù, lati wá kó ikogun nla?

14 Nitorina, sọtẹlẹ, ọmọ enia, si wi fun Gogu pe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Ni ijọ na nigbati awọn enia mi Israeli ba ngbe laibẹ̀ru, iwọ kì yio mọ̀?

15 Iwọ o si ti ipò rẹ wá lati iha ariwa, iwọ, ati ọ̀pọ enia pẹlu rẹ, gbogbo wọn li o ngùn ẹṣin, ẹgbẹ nla, ati ọ̀pọlọpọ ogun alagbara:

16 Iwọ o si goke wá si awọn enia mi Israeli, bi awọsanma lati bò ilẹ; yio si ṣe nikẹhin ọjọ, emi o si mu ọ dojukọ ilẹ mi, ki awọn orilẹ-ède ki o le mọ̀ mi, nigbati a o yà mi si mimọ́ ninu rẹ niwaju wọn, iwọ Gogu.

17 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Iwọ li ẹniti mo ti sọ̀rọ rẹ̀ nigba atijọ lati ọwọ́ awọn iranṣẹ mi awọn woli Israeli, ti nwọn sọtẹlẹ li ọjọ wọnni li ọdun pupọ pe, emi o mu ọ wá dojukọ wọn?

18 Yio si ṣe nigbakanna li àkoko ti Gogu yio wá dojukọ ilẹ Israeli, ni Oluwa Ọlọrun wi, ti irúnu mi yio yọ li oju mi.

19 Nitori ni ijowu mi ati ni iná ibinu mi ni mo ti sọ̀rọ, Nitõtọ li ọjọ na mimì nla kan yio wà ni ilẹ Israeli;

20 Awọn ẹja inu okun, ati awọn ẹiyẹ oju ọrun, ati awọn ẹranko inu igbó, ati ohun gbogbo ti nrakò lori ilẹ, ati gbogbo enia ti mbẹ loju ilẹ, yio si mì niwaju mi, a o si bì òke-nla ṣubu, ati gbogbo ibi giga yio ṣubu, olukuluku ogiri yio ṣubu lulẹ.

21 Emi o si pè idà si i lori gbogbo oke mi, ni Oluwa Ọlọrun wi: idà olukuluku yio si dojukọ arakọnrin rẹ̀.

22 Emi o si fi ajàkalẹ arùn ati ẹjẹ ba a wijọ; emi o si rọ̀ ojò pupọ̀, ati yìnyin nla, iná ati brimstone, si i lori, ati sori awọn ẹgbẹ rẹ̀, ati sori ọ̀pọlọpọ enia ti o wà pẹlu rẹ̀.

23 Emi o si gbe ara mi lèke, emi o si ya ara mi si mimọ́; emi o si di mimọ̀ loju ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède, nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.

## ORI 39.

NITORINA, iwọ ọmọ enia, sọtẹlẹ si Gogu, si wipe, Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Kiye si i, emi dojukọ́ ọ, iwọ Gogu, olori ọmọ-alade Meṣeki ati Tubali:

2 Emi o si dá ọ padà, emi o si dári rẹ, emi o si mu ọ goke wá lati ihà ariwa, emi o si mu ọ wá sori oke giga Israeli:

3 Emi o si lù ọrun rẹ kurò li ọwọ́ osì rẹ, emi o si mu ọfà rẹ bọ kuro lọwọ ọtun rẹ.

4 Iwọ o ṣubu lori òke giga Israeli, iwọ, ati gbogbo awọn ogun rẹ, ati awọn enia ti o wà pẹlu rẹ: emi o fi ọ fun ẹiyẹ ọdẹ onirũru iyẹ, ati ẹranko igbẹ lati pa jẹ.

5 Iwọ o ṣubu ni gbangba oko: nitori emi li o sọ ọ, ni Oluwa Ọlọrun wi.

6 Emi o si rán iná si Magogu, ati sãrin awọn ti ngbe erekuṣu laibẹ̀ru; nwọn o si mọ̀ pe emi li Oluwa.

Digitized by Google

7 Emi o si sọ orukọ mimọ́ mi di mimọ̀
lãrin enia mi Israeli; emi kì yio si jẹ ki
nwọn bà orukọ mimọ́ mi jẹ mọ: awọn
orilẹ-ède yio si mọ̀ pe emi li Oluwa, Ẹni-
Mimọ́ ni Israeli.
8 Kiye si i, o ti de, a si ti ṣe e; ni Oluwa
Ọlọrun wi, eyi ni ọjọ ti emi ti sọ.
9 Awọn ti o si ngbe ilu Israeli yio jade
lọ, nwọn o si fi ohun ihamọra wọnni jona
ati asa ati apata, ọrun ati ọfà, kùmọ ati
ọ̀kọ; nwọn o si fi iná sun wọn li ọdun
meje:
10 Nwọn kì yio lọ rù igi lati inu oko
wá, bẽni nwọn kì yio ke igi lulẹ lati inu
igbọ́ wá; nitori ohun ihamọra ni nwọn ti
fi daná; nwọn o si ko awọn ti o ko wọn,
nwọn o si dọdẹ awọn ti o dọdẹ wọn, ni
Oluwa Ọlọrun wi.
11 Yio si ṣe li ọjọ na, emi o fi ibikan
fun Gogu nibẹ fun iboji ni Israeli, afonifoji
awọn èro ni gabasi okun; on si pa awọn
èro ni ẹnu mọ: nibẹ ni nwọn o gbe
sin Gogu ati gbogbo ọ̀pọlọpọ enia rẹ̀ si:
nwọn o si pè e ni, Afonifoji Hamon-gogu.
12 Oṣù meje ni ile Israeli yio si ma fi
sin okú wọn, ki nwọn ba le sọ ilẹ na di
mimọ́.
13 Gbogbo enia ilẹ na ni yio si sin wọn:
yio si jẹ okiki fun wọn li ọjọ ti a o yìn mi
logo, ni Oluwa Ọlọrun wi.
14 Nwọn o si yà awọn ọkọnrin sọtọ ti
yio ma fi ṣe iṣẹ iṣe, lati ma rìn ilẹ na ja
lati lọ isin awọn erò ti o kù lori ilẹ, lati sọ
ọ di mimọ́: lẹhin oṣù meje nwọn o ma wá
kiri.
15 Awọn èro ti nlà ilẹ na kọja, nigbati
ẹnikan ba ri egungun enia kan, yio sàmi
kan si ẹba rẹ̀, titi awọn asinku yio fi sin i
si afonifoji Hamon-gogu.
16 Orukọ ilu na pẹlu yio si jẹ Hamona.
Bayi ni nwọn o si sọ ilẹ na di mimọ́.
17 Ati iwọ, ọmọ enia, bayi li Oluwa
Ọlọrun wi: Sọ fun olukuluku ẹiyẹ abiyẹ́,
ati fun olukuluku ẹranko igbẹ, pe, Ẹ ko
ara nyin jọ, ki ẹ si wá: ẹ gbá ara nyin jọ
ni ihà gbogbo si ẹbọ mi ti emi rú fun nyin,
ani irubọ nla lori oke giga Israeli, ki ẹnyin
ba le jẹ ẹran, ki ẹ si mu ẹjẹ.
18 Ẹnyin o jẹ ẹran-ara awọn alagbara,
ẹnyin o si mu ẹjẹ awon ọmọ-alade aiye, ti
agbò, ti ọdọ agutan, ati ti obukọ, ti akọ
malũ, gbogbo wọn abọpa Baṣan.
19 Ẹ o si jẹ ọra li ajẹ́yo, ẹ o si mu ẹjẹ li
amupara, lati inu ẹbọ mi ti mo ti rú fun
nyin.
20 Bayi li a o fi ẹṣin ati ẹlẹṣin bọ́ nyin
yo lori tabili mi, pẹlu awọn alagbara, ati
gbogbo awọn ologun, ni Oluwa Ọlọrun
wi.
21 Emi o si gbe ogo mi kalẹ lãrin awọn
keferi, gbogbo awọn keferi yio si ri idajọ
mi ti mo ti ṣe, ati ọwọ́ mi ti mo ti fi le
wọn.
22 Ile Israeli yio si mọ̀ pe, Emi li Oluwa
Ọlọrun wọn lati ọjọ na lọ titi.
23 Awọn keferi yio si mọ̀ pe Israeli lọ si
igbekùn nitori aiṣedẽde wọn: nitoriti nwọn
ti ṣọ̀tẹ si mi, nitorina ni mo ṣe fi oju mi
pamọ kuro lọdọ wọn, ti mo si fi wọn le
awọn ọta wọn lọwọ: gbogbo wọn si ti ipa
idà ṣubu.
24 Gẹgẹ bi aimọ́ wọn, ati gẹgẹ bi irekọja
wọn ni mo ṣe si wọn, mo si fi oju mi pamọ́
kuro lọdọ won.
25 Nitorina bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Nisisiyi li emi o mu igbèkun Jakobu* padà
bọ̀, emi o si ṣãnu fun gbogbo ile Israeli, emi
o si jowu nitori orukọ mi mimọ́.
26 Nwọn o si rù itiju wọn, ati gbogbo
ọ̀tẹ wọn ti nwọn ti ṣe si mi, nigbati nwọn
ngbe laibẹ̀ru ni ilẹ wọn, ti ẹnikẹni kò si
dẹ̀ruba wọn.
27 Nigbati emi ti mu wọn bọ̀ lati ọdọ
orilẹ-ède, ti mo si ko wọn jọ lati ilẹ awọn
ọta wọn wá, ti a si yà mi si mimọ́ ninu
wọn niwaju orilẹ-ède pupọ.
28 Nigbana ni nwọn o mọ̀ pe emi li
Oluwa Ọlọrun wọn, nipa kikó ti mo mu ki
a kó wọn lọ si igbekun lãrin awọn keferi:
ṣugbọn mo ti ṣà wọn jọ si ilẹ wọn, emi kò
si fi ẹnikẹni wọn silẹ nibẹ mọ.
29 Emi kì yio si fi oju mi pamọ kuro
lọdọ wọn mọ: nitori emi ti tú ẹmi mi sori
ile Israeli, ni Oluwa Ọlọrun wi.

## ORI 40.

LI ọdun kẽdọgbọn oko-ẹrù wa, ni ibẹ̀rẹ
ọdun na, li ọjọ ikẹwa oṣù, li ọdun
ikẹrinla lẹhin igbati ilu fọ́, li ọjọ na gan,
ọwọ́ Oluwa wà lara mi, o si mu mi wá sibẹ
na.
2 Ninu iran Ọlọrun li o mu mi wá si ilẹ
Israeli, o si gbe mi ka oke giga kan, lori
eyiti kikọ ilu wà ni iha gusu.
3 O si mu mi wá sibẹ, si kiyesi i, ọkọn-
rin kan mbẹ, ẹniti irí rẹ̀ dabi irí bàba, pẹlu
okùn ọ̀gbọ li ọwọ́ rẹ̀, ati ije iwọ̀nlẹ; on si
duro ni ẹnu-ọ̀na.
4 Ọkọnrin na si wi fun mi pe, Ọmọ
enia, fi oju rẹ wò, ki o si fi eti rẹ gbọ́, ki o
si gbe ọkán rẹ le ohun gbogbo ti emi o fi

Digitized by Google

hàn ọ: nitori ka ba le fi wọn han ọ li a ṣe
mu ọ wá ihinyi: sọ ohun gbogbo ti o ri fun
ile Israeli.
5 Si kiye si i, ogiri kan mbẹ lode ile na
yika, ije iwọ̀nlẹ kan si mbẹ lọwọ ọkọnrin
na, igbọnwọ mẹfa, nipa igbọnwọ ati ibú
atẹlẹwọ kan: o si wọ̀n ibú ile na, ije kan;
ati giga rẹ̀, ije kan.
6 Nigbana li o wá si ẹnu-ọ̀na ti o kọju
si ọ̀na gabasi, o si gùn oke atẹ̀gun na lọ, o
si wọ̀n iloro ẹnu-ọ̀na, ti o jẹ ije kan ni ibú;
ati iloro miran ti ẹnu-ọ̀na na, ti o jẹ ije
kan ni ibú.
7 Yará kékèké si jẹ ije kan ni gigùn, ati
ije kan ni ibú; ati lãrin yará kékèké igbọn-
wọ marun; àtẹwọ enu-ọ̀na lẹba iloro ẹnu-
ọ̀na ti inu si jẹ ije kan.
8 O si wọ̀n iloro ẹnu-ọ̀na ti inu, ije
kan.
9 O si wọ̀n iloro ẹnu-ọ̀na, igbonwọ mẹjọ;
ati atẹrigba rẹ̀, igbọnwọ mejimeji; iloro ti
ẹnu-ọ̀na na si mbẹ ninu.
10 Ati yará kékèké ẹnu-ọ̀na ti ọ̀na ga-
basi jẹ mẹta nihà ìhin, ati mẹta nihà ọhún;
awọn mẹtẹta jẹ ìwọn kanna: awọn atẹri-
gba na jẹ ìwọn kanna niha ìhin ati niha
ọhún.
11 O si wọ̀n ibu abawọle ẹnu-ọ̀na na,
igbọnwọ mẹwa; ati gigùn ẹnu-ọ̀na na,
igbọnwọ mẹtala.
12 Àye ti si mbẹ niwaju awọn yará ké-
kèké na jẹ igbọnwọ kan nihà ìhin, àye na
si jẹ igbọnwọ kan nihá ọhún; awọn yará
kékèké na si jẹ igbọnwọ mẹfa nihà ìhin,
ati igbọnwọ mẹfa niha ọhún.
13 O si wọ̀n ẹnu-ọ̀na na lati orule yará
kékèké kan lọ de orule miran: ibú rẹ jẹ
igbọnwọ mẽdọgbọn, ilẹkùn dojukọ ilẹkùn.
14 O si ṣe atẹrigba ọlọgọta igbọnwọ,
ani titi de atẹrigba àgbalá yi ẹnu-ọ̀na na
ka.
15 Lati iwaju ẹnu-ọ̀na àtẹwọ titi fi de
iwaju iloro ẹnu-ọ̀na ti inu, adọta igbọnwọ.
16 Awọn ferese tóro si mbẹ lara yará ké-
kèké na, ati lara atẹrigba wọn ninu ẹnu-
ọ̀na niha gbogbo ati pẹlu yará iloro: ferese
pupọ si mbẹ niha inu gbogbo: igi ọpẹ si
mbẹ lara olukuluku atẹrigbà.
17 O si mu mi wá si agbala ode, si ki-
yesi i, ọ̀pọlọpọ yará mbẹ nibẹ, a si fi okuta
tẹ́ agbala na niha gbogbo: ọgbọ̀n yará ni
mbẹ lori okuta itẹlẹ na.
18 Ati okuta itẹlẹ ti iha ẹnu-ọ̀na na ti
o kọju si gigun ẹnu-ọ̀na, ani okuta itẹlẹ
isalẹ.
19 O si wọ̀n ibú rẹ̀ lati iwaju ẹnu-ọ̀na
isalẹ titi fi de iwaju àgbala inu ti ode,
ọgọrun igbọnwọ niha gabasi ati niha ariwa.
20 Ẹnu-ọ̀na àgbala ode ti o kọju si ariwa,
o wọ̀n gigun rẹ̀, ati ibu rẹ̀.
21 Awọn yará kékèké ibẹ̀ jẹ mẹta niha
ìhin, mẹta nihà ọhún; awọn atẹrigba ibẹ
ati iloro ibẹ jẹ gẹgẹ bi ìwọn ẹnu-ọ̀na ekini:
gigùn rẹ̀ jẹ ãdọta igbọnwọ, ibú rẹ̀ si jẹ
igbọnwọ mẽdọgbọ̀n.
22 Ati fèrese wọn, ati iloro wọn, ati igi
ọpẹ wọn jẹ gẹgẹ bi ìwọn ti ẹnu-ọ̀na ti o
kọju si ọ̀na gabasi; nwọn si ba atẹgun
meje gùn oke rẹ̀ lọ; awọn iloro na si mbẹ
niwaju wọn.
23 Ati ẹnu-ọ̀na agbala inu ti o kọju si
ẹnu-ọ̀na ti ariwa, ati ti gabasi; o si wọ̀n
lati ẹnu-ọ̀na de ẹnu-ọ̀na, ọgọrun igbọnwọ.
24 O si mu mi lọ si ọ̀na gusù, si kiye si
i, ẹnu-ọ̀na kan mbẹ li ọ̀na gusù: o si wọ̀n
awọn atẹrigba wọn, ati ìloro wọn gẹgẹ bi
ìwọn wọnyi.
25 Férese pupọ si mbẹ ninu rẹ̀ ati ninu
iloro wọn yika, bi ferese wọnni: gigùn rẹ̀
jẹ ãdọta igbọnwọ, ibú rẹ̀ jẹ igbọnwọ mẽdọ-
gbọn.
26 Atẹ̀gun meje ni mbẹ lati bá gùn oke
rẹ̀, ati awọn iloro rẹ̀ si mbẹ niwaju wọn: o
si ni igi ọpẹ, ọkan nihà ìhin, ati ọkan nihà
ọhún, lara awọn atẹrigbà rẹ̀.
27 Ati ẹnu-ọ̀na agbalá ti inu mbẹ li ọ̀na
gusu; o si wọ̀n lati ẹnu-ọ̀na de ẹnu-ọ̀na li
ọ̀na gusu, ọgọrun igbọnwọ.
28 O si mu mi wá si agbalá ti inu nipa
ẹnu-ọ̀na gusu: o si wọ̀n ẹnu-ọ̀na gusu na
gẹgẹ bi ìwọn wọnyi;
29 Ati awọn yará kékèké rẹ̀, ati atẹ-
rigbà rẹ̀, ati iloro rẹ̀, gẹgẹ bi ìwọn wọnyi:
ferese pupọ̀ si mbẹ nibẹ ati ni iloro rẹ̀ yika:
o jẹ ãdọta igbọnwọ ni gigùn, igbọnwọ mẽ-
dọgbọn ni ibú.
30 Awọn iloro ti mbẹ yika jẹ igbọnwọ
mẽdọgbọ̀n ni gigùn, ati igbọnwọ marun ni
ibú.
31 Awọn iloro rẹ̀ mbẹ nihà agbalá ode;
igi ọpẹ si mbẹ lara atẹrigbà rẹ̀: abágòke rẹ̀
si ní atẹ̀gun mẹjọ.
32 O si mu mi wá si agbalá ti inu nihà
ọ̀na gabasi: o si wọ̀n ẹnu-ọ̀na na, gẹgẹ bi
iwọn wọnyi.
33 Ati yara kékèké rẹ̀, ati atẹrigbà rẹ̀,
ati iloro rẹ̀, jẹ gẹgẹ bi ìwọn wọnyi: ferese
si mbẹ ninu rẹ̀ ati ninu awọn iloro rẹ̀ yika:
o jẹ ãdọta igbọnwọ ni gigùn, ati igbọnwọ
mẽdọgbọn ni ibú.
34 Awọn iloro rẹ̀ mbẹ nihà agbalá ode;
igi ọpẹ si mbẹ lara atẹrigbà rẹ̀, nihà ìhin.

Digitized by Google

ati nihà ọ̀hun: abagòke rẹ̀ si ni atẹ̀gun mẹ́jọ.
35 O si mu mi wá si ẹnu-ọ̀na ariwa, o si wọ̀n ọ gẹgẹ bi ìwọn wọnyi;
36 Awọn yará kékèké rẹ̀, atẹrigbà rẹ̀, ati iloro rẹ̀, ati ferese rẹ̀ yika: gigùn rẹ̀ jẹ ãdọta igbọnwọ, ati ibu rẹ̀ igbọnwọ mẽdọ-gbọ̀n.
37 Ati atẹrigba rẹ̀ mbẹ niha agbalá ode; igi ọpẹ si mbẹ lara atẹrigba rẹ̀, niha ìhin, ati niha ọ̀hun: abagòke rẹ̀ si ní atẹ̀gun mẹ́jọ.
38 Ati yàra ati abáwọle rẹ̀ wà nihà atẹ-rigbà ẹnu-ọ̀na na, nibiti nwọn ima wẹ̀ ọrẹ ẹbọ sisun.
39 Ati ni iloro ẹnu-ọ̀na na tabili meji mbẹ nihà ìhin, ati tabili meji nihà ọ̀hun, lati ma pa ẹran ẹbọ sisun, ati ọrẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ọrẹ ẹbọ irekọja lori wọn.
40 Ati ni ihà ode, bi a ba nlọ si àbáwọle ẹnu-ọ̀na ariwa, ni tabili meji mbẹ; ati nihà miran, ti iṣe iloro ẹnu-ọ̀na, ni tabili meji mbẹ.
41 Tabili mẹrin mbẹ nihà ìhin, tabili mẹrin si mbẹ nihà ọ̀hun, nihà ẹnu-ọ̀na; tabili mẹ́jọ, lori eyiti nwọn a ma pa ẹran ẹbọ wọn.
42 Tabili mẹrin na si jẹ ti okuta gbigbẹ́ fun ọrẹ ẹbọ sisun, igbọnwọ kan on ãbọ ni gigùn, ati igbọnwọ kan on ãbọ ni ibú, ati igbọnwọ kan ni giga: lori eyiti nwọn a si ma kó ohun-elò wọn le, ti nwọn ifi pa ọrẹ ẹbọ sisun ati ẹran ẹbọ.
43 Ati ninu ni ìwọ ẹlẹnu meji, oníbu atẹlẹwọ kan, ti a kàn mọ ọ yika: ati lori awọn tabili na ni ẹran ọrẹ gbe wà.
44 Ati lode ẹnu-ọ̀na ti inu ni yará awọn akọrin gbe wà, ninu agbala ti inu, ti mbẹ ni ihà ẹnu-ọ̀na ariwa; oju wọn si wà li ọ̀na gusu: ọkan ni iha ẹnu-ọ̀na gabasi, oju eyiti mbẹ li ọ̀na ariwa.
45 O si wi fun mi pe, Yàrá yi, ti oju rẹ̀ mbẹ li ọ̀na gusu, ni fun awọn alufa, awọn olutọjú iṣọ ile na.
46 Yará ti oju rẹ̀ mbẹ li ọ̀na ariwa, ni fun awọn alufa, awọn olutọjú iṣọ pẹpẹ na; awọn wọnyi li awọn ọmọ Sadoku ninu awọn ọmọ Lefi, ti nwọn ima sunmọ Oluwa lati ṣe iranṣẹ fun u.
47 O si wọ̀n agbalá na, ọgọrun igbọnwọ ni gigùn, ọgọrun igbọnwọ ni ibú, igun mẹrin lọgbọgba; ati pẹpẹ ti mbẹ niwaju ile na.
48 O si mu mi wá si iloro ile na, o si wọ̀n opo iloro na, igbọnwọ marun nihà ìhin, ati igbọnwọ marun nihà ọ̀hun: ibu ẹnu-ọ̀na na si jẹ̀ igbọnwọ mẹta nihà ìhin, ati igbọnwọ mẹta nihà ọ̀hun.
49 Gigùn iloro na jẹ ogún igbọnwọ, ibú rẹ̀ igbọnwọ mọkànla; o si mu mi wá si atẹ̀gun ti nwọn ifi ba gokè rẹ̀: ọwọ̀n pupọ̀ si mbẹ nihà ibi atẹrigbà, ọkan nihin, ati ọkan lọhun.

## ORI 41.

O SI mu mi wá si tempili, o si wọ̀n awọn atẹrigbà, igbọnwọ mẹfa ni gbigborò li apakan, igbọnwọ mẹfa ni gbigborò li apakeji, ibú agọ na.
2 Ati ibú ilẹkùn na jẹ igbọnwọ mẹwa; ihà ilẹkùn na si jẹ igbọnwọ marun li apakan, ati igbọnwọ marun li apakeji; o si wọ̀n gigùn rẹ̀, ogoji igbọnwọ; ati ibú rẹ̀, ogún igbọnwọ.
3 O si wá si inu rẹ̀, o si wọ̀n atẹrigbà ilẹkùn na, igbọnwọ meji; ati ilẹkùn na, igbọnwọ mẹfa; ibú ilẹkùn na si jẹ igbọn-wọ meje.
4 Bẹ̃ li o si wọ̀n gigùn rẹ̀, ogún igbọnwọ; ati ibú rẹ̀, ogún igbọnwọ, niwaju tempili: o si wi fun mi pe, Eyi ni ibi mimọ́ julọ.
5 O si wọ̀n ogiri ile na, igbọnwọ mẹfa; ati ibú yàrá-ihà gbogbo igbọnwọ mẹrin, yi ile na ka nihà gbogbo.
6 Ati awọn yará-ihà, ọkan lori ekeji jẹ mẹta, nigba ọgbọ̀n: nwọn si wọ̀ inu ogiri ti ile awọn yará-ihà na yika, ki nwọn ba le di ara wọn mu, nitori kò si idimú ninu ogiri ile na.
7 A si ṣe e gborò, o si lọ yika loke awọn yará ihà: nitori ogiri ile na lọ loke-loke yi ile na ka: nitorina ibú ile na wà loke, bẹ̃ni iyará isalẹ yọ si toke lãrin.
8 Emi si ri giga ile na yika: ipilẹ awọn yará-iha na si jẹ ije kikun kan ti igbọnwọ mẹfa ni gigun.
9 Ibú ogiri na, ti yará-iha lode, jẹ igbọn-wọ marun: ati eyi ti o kù ni ibi yará-iha ti mbẹ ninu.
10 Ati lãrin yará na, ogún igbọnwọ ni gbigborò, yi ile na ka ni ihà gbogbo.
11 Ati ilẹkùn awọn yará-ihà na mbẹ li ọ̀na ibi ti o kù, ilẹkùn kan li ọ̀na ariwa, ati ilẹkùn kan ni gusu: ati ibú ibẹ̀ na ti o kù, jẹ igbọnwọ marun yika.
12 Ati ile ti o wà niwaju eyiti a yà sọtọ̀ ni igun ọ̀na yama, jẹ ãdọrin igbọnwọ ni gbigborò; ogiri ile na si jẹ igbọnwọ marun ni ibú yika, ati gigùn rẹ̀, ãdọrun igbọnwọ.
13 O si wọ̀n ile na, ọgọrun igbọnwọ ni gigùn; ati ibi ti a yà sọtọ̀, ati ile na, pẹlu ogiri wọn, ọgọrun igbọnwọ ni gigùn.

Digitized by Google

14 Ati ibú oju ile na, ati ti ibi ti a yà
sọtọ̀ nihà gabasi ọgọrun igbọnwọ.
15 O si wọ̀n gigun ile na ti o kọju si
ibiti a yà sọtọ̀ ti mbẹ lẹhin rẹ̀, ati ibujoko-
oke ni ihà kan ati nihà miran, ọgọrún
igbọnwọ, pẹlu tempili inu, ati iloro agbalá
na ;
16 Awọn iloro, ati ferese toro, ati ibujoko
oke yika lori ile olorule mẹta wọn, ti o wà
niwaju iloro na, li a fi igi tẹ́ yika, ati lati
ilẹ de oke ferese, a si bò awọn ferese na ;
17 Si ti oke ilẹkun ani titi de ile ti inu,
ati ti ode, ati lara ogiri niha gbogbo tinu
tode ni wiwọ̀n.
18 Kerubimu ati igi ọpẹ li a si fi ṣe e, igi
ọpẹ kan si mbẹ lãrin kerubu ati kerubu :
kerubu kọkan si ni oju meji ;
19 Oju enia kan si wà nihà ibi igi ọpẹ li
apa kan, ati oju ẹgbọ̀rọ kiniun kan si wà
nihà ibi igi ọpẹ li apa keji : a ṣe e yi ile na
ka niha gbogbo.
20 Lati ilẹ titi fi de okè ilẹkùn, ni a ṣe
kerubimu ati igi ọpẹ si, ati lara ogiri
tempili na.
21 Awọn opó ilẹkùn tempeli na jẹ igun
mẹrin lọgbọgba : ati iwaju ibi mimọ́, irí
ọkan bi irí ekeji.
22 Pẹpẹ igi na jẹ igbọnwọ mẹta ni giga,
gigùn rẹ̀ igbọnwọ meji ; ati igun rẹ̀, ati
gigùn rẹ̀, ati awọn ogiri rẹ̀ jẹ ti igi : o si wi
fun mi pe, Eyi ni tabili ti mbẹ niwaju
Oluwa.
23 Ati tempili na, ati ibi mimọ́ na, ni
ilẹkùn meji.
24 Awọn ilẹkùn mejeji na ni awẹ, awẹ
meji ti nyi ; awẹ meji fun ilẹkùn kan, ati
awẹ meji fun ilẹkùn keji.
25 Kerubimu ati igi ọpẹ li a ṣe si ara
wọn, sara ilẹkùn tempili, gẹgẹ bi eyiti a
ṣe sara ogiri ; igi ibori wà loju iloro lode.
26 Ferese toro ati igi ọpẹ mbẹ nihà ihin
ati nihà ọhun nihà iloro, ati ni yará-iha ile
na, ati ni igi ibori.

## ORI 42.

O SI mu mi wá si agbala ode, li ọ̀na apa
ariwa : o si mu mi wá si yará ti o kọju si
ibi ti a yà sọtọ̀, ti o si kọju si ile lọna ariwa.
2 Niwaju, ọgọrun igbọnwọ ni gigùn ni
ilẹkun ariwa, ati ibú rẹ̀ ãdọta igbọnwọ.
3 Niwaju, ogún igbọnwọ ti o wà fun
agbalá ti inu, ati niwaju itẹle ti o wà fun
agbalá ti ode ; ibujoko oke ti o kọju si ibu-
joko-oke wà ni orule mẹta.
4 Ati niwaju awọn yará ni irin igbọnwọ
mẹwa ni ibú ninu, ọ̀na igbọnwọ kan ; ilẹ-
kùn wọn si wà nihà ariwa.
5 Ati awọn yará oke kuru jù ; nitori
ibujoko ti awọn yará isalẹ ati yará ãrin yọ
siwaju wọnyi ti ile.
6 Nitori nwọn jẹ olorule mẹta, ṣugbọn
nwọn kò ni ọwọ̀n bi ọwọ̀n agbalá : nito-
rina a fasẹhin kuro ninu yará isalẹ ati
kuro ninu yará ãrin lati ilẹ wá.
7 Ati ogiri ti o wà lode ti o kọju si yará,
li apa agbala ode niwaju yará, gigùn rẹ̀ jẹ
ãdọta igbọnwọ.
8 Nitori gigùn awọn yará ti o wà lode jẹ
ãdọta igbọnwọ : si wò o, niwaju tempili o
jẹ ọgọrun igbọnwọ.
9 Ati lati isalẹ yará wọnyi ni iwọle li
ọ̀na gabasi wà, bi a ti nlọ sinu wọn lati
agbala ode wá.
10 Ni ibú ogiri agbala, li ọ̀na gabasi
niwaju ibiti a yà sọtọ̀, ati niwaju ile na, ni
awọn yará na wà.
11 Ati ọ̀na iwaju wọn ri gẹgẹ bi iri awọn
yará ti o wà li ọ̀na ariwa, bi nwọn ti gùn
mọ, bẹ̃ ni nwọn gbòro mọ : ati gbogbo
ijade wọn si dabi iṣe wọn, ati bi ilẹkùn
wọn.
12 Bẹ̃ gẹgẹ ni yará ti on ti ilẹkùn wọn li
ọ̀na gusu, ilẹkùn kan wà lori ọ̀na, li ọ̀na
gbọran niwaju ogiri li ọ̀na gabasi bi a ti
nwọ̀ inu wọn.
13 O si wi fun mi pe, Awọn yará ariwa
ati awọn yará gusu, ti o wà niwaju ibiti a
yà sọtọ̀, awọn ni yará mimọ́, nibiti awọn
alufa ti nsunmọ Oluwa yio ma jẹ ohun
mimọ́ julọ : nibẹ̀ ni nwọn o ma gbe ohun
mimọ́ julọ kà, ati ọrẹ ẹbọ jijẹ, ati ọrẹ ẹbọ
ẹ̀ṣẹ, ati ọrẹ ẹbọ irẹkọja ; nitori ibẹ̀ jẹ mimọ́.
14 Nigbati awọn alufa ba wọ̀ ibẹ̀, nwọn
kì yio si kuro ni ibi mimọ́ si agbala ode,
ṣugbọn nibẹ nibiti nwọn gbe nṣiṣẹ ni nwọn
o fi ẹwù wọn si ; nitori nwọn jẹ mimọ́ ;
nwọn o si wọ̀ ẹwù miran, nwọn o si sunmọ
nkan wọnni ti o jẹ́ ti enia.
15 Nigbati o si ti wọ̀n ile ti inu tan, o
mu mi wá sihà ilẹhùn ti o kọju si ọ̀na
gabasi, o si wọ̀n yika.
16 O fi ije iwọ̀nlẹ wọ̀n ti apa gabasi,
ẽdẹgbẹta ije, nipa ije iwọ̀nlẹ yika.
17 O si fi ije iwọ̀nlẹ wọ̀n ti apa ariwa,
ẽdẹgbẹta ije yika.
18 O si fi ije iwọ̀nlẹ wọ̀n ti apa gusu,
ẽdẹgbẹta ije.
19 O yipadà si ọ̀na yama, o si fi ije
iwọ̀nlẹ wọ̀n ọ, ẹ̀dẹgbẹta ije.
20 O wọ̀n ọ nihà mẹrẹrin : o ni ogiri
kan yi i ka, ẽdẹgbẹta ije ni gigùn, ati ẽdẹ-

Digitized by Google

gbęta ni ibú, lati pàla lãrin ibi mimọ́ ati
ibi aimọ́.

## ORI 43.

OSI mu mi wá si ẹnu-ọ̀na, ẹnu-ọ̀na ti o
kọjusi ọ̀na gabasi:
2 Si kiyesi i, ogo Ọlọrun Israeli wá lati
ọ̀na gabasi: ati ohùn rẹ̀ ri bi ariwo omi
pupọ̀: aiye si ràn fun ogo rẹ̀.
3 O si dabi irí iran ti mo ri, gẹgẹ bi iran
ti mo ri nigbati mo wá lati pa ilu na run:
iran na si dabi iran ti mo ri lẹba odò Kebari,
mo si doju mi bolẹ.
4 Ogo Oluwa si wá si ile na lati ọ̀na ilẹ-
kùn ti o kọjusi ọ̀na gabasi.
5 Ẹmi si gbe mi soke, o si mu mi wá si
àgbala tinu: si kiye si i, ogo Oluwa kún
ile na.
6 Mo si gbọ́ o mba mi ṣọ̀rọ lati inu ile
wá; ọkọnrin na si duro tì mi.
7 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, ibi itẹ
mi, ati ibi atẹlẹṣẹ mi, nibiti emi o gbe
lãrin awọn ọmọ Israeli lailai, ati orukọ
mimọ́ mi, ni ki ile Israeli má bajẹ mọ, awọn,
tabi ọba wọn, nipa panṣaga wọn, tabi nipa
okú ọba wọn ni ibi giga wọn.
8 Ni titẹ́ iloro wọn nibi iloro mi, ati opó
wọn nibi opó mi, ogiri si wà lãrin emi ati
awọn, nwọn si ti ba orukọ mimọ́ mi jẹ
nipa ohun irira wọn ti nwọn ti ṣe: mo si
run wọn ni ibinu mi.
9 Njẹ ki nwọn mu panṣaga wọn, ati okú
ọba wọn jina kurò lọdọ mi, emi o si ma gbe
ãrin wọn lailai.
10 Iwọ ọmọ enia, fi ile na hàn ile Israeli,
ki oju aiṣedede wọn ba le tì wọn: si jẹ ki
nwọn wọ̀n apẹrẹ na.
11 Bi oju gbogbo ohun ti nwọn ba ṣe ba
si tì wọn, fi irí ile na hàn wọn, ati kikọ́ rẹ̀,
ati ijade rẹ̀, ati iwọle rẹ̀, ati gbogbo irí rẹ̀,
ati gbogbo aṣẹ rẹ̀, ati gbogbo irí rẹ̀, ati
gbogbo ofin rẹ̀; ki o si kọ ọ loju wọn,
ki nwọn ki o lè pa gbogbo irí rẹ̀ mọ, ati
gbogbo aṣẹ rẹ̀, ki nwọn si ṣe wọn.
12 Eyi ni ofin ile na; Lori oke giga,
gbogbo ipinnu rẹ̀ yika ni mimọ́ julọ.
Kiyesi i, eyi ni ofin ile na.
13 Wọnyi si ni iwọ̀n pẹpẹ nipa igbọnwọ;
Igbọnwọ jẹ igbọnwọ kan ati ibú atẹlẹwọ
kan; isalẹ rẹ̀ yio jẹ igbọnwọ kan, ati ibu rẹ̀
igbọnwọ kan, ati igbati rẹ̀ ni eti rẹ̀ yika
yio jẹ ika kan: eyi ni yio si jẹ ibi giga
pẹpẹ na.
14 Lati isalẹ ilẹ titi di ijoko isalẹ yio jẹ
gbọnwọ meji, ati ibú rẹ̀ igbọnwọ́ kan; ati
lati ijoko kekere titi de ijoko nla yio jẹ
igbọnwọ mẹrin, ati ibú rẹ̀ igbọnwọ kan.
15 Pẹpẹ na si jẹ igbọnwọ mẹrin: ati lati
pẹpẹ titi de oke jẹ iwo mẹrin.
16 Pẹpẹ na yio si jẹ igbọnwọ mejila ní
gigùn, ati mejila ni ibú onigun mẹrin ni
igun mẹrẹrin rẹ̀.
17 Ati ijoko ni yio jẹ igbọ̀nwọ mẹrinla
ni gigun ati mẹrinla ni ibu ninu igun mẹ-
rẹrin rẹ̀; ati eti rẹ̀ yika yio jẹ́ abọ̀ igbọnwọ;
ati isalẹ rẹ̀ yio jẹ igbọnwọ kan yika; atẹ-
gùn rẹ̀ yio si kọjusi iha gabasi.
18 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, bayi li
Oluwa Ọlọrun wi; Eyi ni aṣẹ pẹpẹ na li
ọjọ ti nwọn o ṣe e, lati rú ọrẹ ẹbọ sisun lori
rẹ̀, ati lati wọ́n ẹ̀jẹ sori rẹ̀.
19 Iwọ o si fi ẹgbọrọ malu, fun ọrẹ ẹbọ
ẹ̀ṣẹ, fun awọn alufa, awọn Lefite, ti iṣe iru-
ọmọ Sadoku, ti nsunmọ mi, lati ṣe iranṣẹ
fun mi, ni Oluwa Ọlọrun wi.
20 Iwọ o si mu ninu ẹjẹ rẹ̀, iwọ o si fi sí
iwo mẹrẹrin rẹ̀, ati si igun mẹrẹrin ijoko na,
ati si eti rẹ̀ yika: iwọ o si wẹ̀ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọ́,
iwọ o si ṣe etùtu rẹ̀.
21 Iwọ o si mu ẹgbọrọ malu ti ọrẹ ẹbọ
ẹ̀ṣẹ, on o si sun u ni ibiti a yàn ni ilẹ na
lode ibi-mimọ́.
22 Ati ni ọjọ keji iwọ o fi ọmọ ewurẹ
alailabawọn rubọ ọrẹ ẹ̀ṣẹ; nwọn o si sọ
pẹpẹ na di mimọ́, bi nwọn iti ifi ẹgbọrọ
malu sọ ọ di mimọ́.
23 Nigbati iwọ ba ti sọ ọ di mimọ tan,
iwọ o fi ẹgbọrọ malu alailabawọn rubọ, ati
àgbo alailabawọn lati inu agbo wá.
24 Iwọ o si fi wọn rubọ niwaju Oluwa,
awọn alufa yio si dà iyọ̀ si wọn, nwọn o si
fi wọn rú ọrẹ ẹbọ sisun si Oluwa.
25 Ọjọ meje ni iwọ o fi pèse obukọ fun
ọrẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ lojojumọ: nwọn o si pèse ẹgbọrọ
malu pẹlu ati àgbo lati inu agbo wá, ti
nwọn ṣe ailabawọn.
26 Ọjọ meje ni nwọn o fi wẹ̀ pẹpẹ, nwọn
o si sọ ọ di mimọ́: nwọn o si yà ara wọn
sọtọ̀.
27 Nigbati ọjọ wọnyi ba pe, yio si ṣe,
ni ọjọ kẹjọ, ati siwaju, awọn alufa yio ṣe
ọrẹ ẹbọ sisun nyin lori pẹpẹ, ati ọrẹ ẹbọ
idupẹ: emi o si gbà nyin, ni Oluwa Ọlọrun
wi.

## ORI 44.

OSI mu mi pada lọna ẹnu-ọ̀na ibi-mimọ́
ti ode ti o kọju si gabasi; o si tì.
2 Oluwa si wi fun mi pe; Ẹnu-ọ̀na yi
yio wà ni titì, a kì yio ṣi i, ẹnikan kì yio si

Digitized by Google

gbà a wọ inu rẹ̀; nitori Oluwa, Ọlọrun
Israeli, ti gbà a wọ inu rẹ̀, yio si wà ni titì.
3 Fun ọmọ-alade ni; ọmọ-alade, on ni
yio joko ninu rẹ̀ lati jẹ akara niwaju
Oluwa; yio wọ̀ ọ lati ọ̀na iloro ẹnu-ọ̀na na,
yio si jade lati ọ̀na rẹ̀ na lọ.
4 O si mu mi wá ọ̀na ẹnu-ọ̀na ariwa
siwaju ile na; mo si wò, si kiyesi i, ogo
Oluwa kun ile Oluwa: mo si doju mi bolẹ.
5 Oluwa si wi fun mi pe, Ọmọ enia, fi
iyè rẹ si i, si fi oju rẹ wò, si fi eti rẹ gbọ́
ohun gbogbo ti emi ti sọ fun ọ niti gbogbo
aṣẹ ile Oluwa, ati ti gbogbo ofin rẹ̀; si fi
iyè rẹ si iwọ̀nu ile nì, pẹlu gbogbo ijadelọ
ibi-mimọ́ na.
6 Iwọ o si wi fun awọn ọlọ̀tẹ, ani fun
ile Israeli, pe, Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi;
ki gbogbo ohun-irira nyin to fun nyin, ile
Israeli,
7 Niti ẹ mu ọmọ-ajẹ̀ji, alaikọla aiya, ati
alaikọla ara wa, lati wà ni ibi-mimọ́ mi,
lati sọ ọ di alailọ̀wọ, ani ile mi, nigbati ẹ
rú akara mi, ọ̀ra ati ẹjẹ, nwọn si bà majẹmu
mi jẹ nipa gbogbo ohun-irira nyin.
8 Ẹ kò si pa ibi-iṣẹ́ ohun-mimọ́ mi mọ́:
ṣugbọn ẹ ti yàn oluṣọ́ ibi-iṣẹ́ inu ibi-mimọ́
mi fun ara nyin.
9 Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi: Gbogbo
ọmọ àjeji, alaikọla aiya, tabi alaikọla ara
kì yio wọ̀ inu ibi mimọ́ mi, ninu gbogbo
ọmọ àjeji ti o wà lãrin awọn ọmọ Israeli.
10 Ṣugbọn awọn Lefite ti o ti lọ jina
kuro lọdọ mi, ñi ìṣina Israeli, ti nwọn ṣìna
kuro lọdọ mi lẹhin oriṣa wọn: yio si rù
aiṣedede wọn.
11 Nwọn o si jẹ iranṣẹ ni ibi mimọ́ mi,
oluṣọ́ ẹnu-ọ̀na ile, nwọn o si ma ṣe iranṣẹ
ni ile: awọn ni yio pa ọrẹ-ẹbọ sisun ati ẹbọ
fun awọn enia, nwọn o si duro niwaju wọn
lati ṣe iranṣẹ fun wọn.
12 Nitori ti nwọn ṣe iranṣẹ fun wọn
niwaju òriṣa wọn, nwọn si jẹ ohun ìdugbolu
aiṣedede fun ile Israeli: nitorina ni mo gbe
ọwọ́ mi soke si wọn, ni Oluwa Ọlọrun wi,
nwọn o si rù aiṣedede wọn.
13 Nwọn kì yio si sunmọ ọdọ mi, lati
ṣiṣẹ alufa fun mi, tabi lati sunmọ gbogbo
ohun-mimọ́ mi, ni ibi mimọ́ julọ: nwọn o
si rù itijú wọn, ati ohun-irira wọn ti nwọn
ti ṣe.
14 Emi o si ṣe wọn ni oluṣọ́ ibi-iṣẹ́ ile,
fun gbogbo iṣẹ rẹ̀, ati fun ohun gbogbo ti a
o ṣe ninu rẹ̀.
15 Ṣugbọn awọn alufa awọn Lefite, awọn
ọmọ Sadoku, ti o pa ibi-iṣọ ibi-mimọ́ mi
mọ, nigbati awọn ọmọ Israeli ṣìna kuro
lọdọ mi, awọn ni yio sunmọ ọdọ mi lati ṣe
iranṣẹ fun mi, nwọn o si duro niwaju mi
lati rú ọrá ati ẹjẹ si mi, ni Oluwa Ọlọrun
wi:
16 Awọn ni yio wá si ibi-mimọ́ mi, awọn
ni o si sunmọ tabili mi, lati ṣe iranṣẹ fun
mi, nwọn o si pa ibi-iṣọ́ mi mọ́.
17 Yio si ṣe pe, nigbati nwọn ba wá si
ẹnu-ọ̀na agbalá ti inu, nwọn o wọ̀ ẹ̀wu
ọ̀gbọ; irun agutan kì yio bọ́ si ara wọn,
nigbati nwọn ba nṣe iranṣẹ ni ẹnu-ọ̀na
agbalá ti inu, ati ninu ile.
18 Nwọn o si ni filà ọ̀gbọ li ori wọn,
ṣòkoto ọ̀gbọ ni nwọn o si wọ̀ ni idí wọn;
nwọn kì o si fi ohun ti imuni lãgùn dì
amurè.
19 Nigbati nwọn ba si lọ si agbalá ode,
ani si agbalá ode sọdọ awọn enia, nwọn o
bọ́ ẹ̀wu wọn ti nwọn ifi ṣe iranṣẹ, nwọn o si
fi wọn si awọn yará mimọ́, nwọn o si wọ̀
ẹ̀wu miran; nwọn kì yio si fi ẹ̀wu wọn sọ
awọn enia di mimọ́.
20 Nwọn kì o si fá ori wọn, bẹ̃ni nwọn
kì yio jẹ ki irun wọn gbọ̀; ni rirẹ nwọn o
rẹ irun ori wọn.
21 Alufa gbogbo kì yio mu ọti-waini,
nigbati awọn ba wá si agbalá ti inu.
22 Nwọn kì yio si fẹ́ opo, tabi ẹniti a
tì jade fun aya wọn: ṣugbọn nwọn o fẹ́
wundia lati iru-ọmọ ile Israeli, tabi opo ti
o ti ni alufa ri.
23 Nwọn o si kọ́ awọn enia mi ni iyàtọ
ti o wà lãrin mimọ́ ati ailọ̀wọ, nwọn o si
mu wọn mọ̀ eyiti a wà lãrin aimọ́ ati mimọ́.
24 Ati ni ija, awọn ni yio duro lati ṣe
idajọ; nwọn o si dá a ni idajọ mi: nwọn o
si pa ofin mi ati aṣẹ mi mọ́ ni gbogbo apejọ
mi; nwọn o si yà awọn ọjọ isimi mi si
mimọ́.
25 Nwọn kì yio si wá sọdọ okú enia lati
sọ ara wọn di aimọ́, ṣugbọn fun baba, tabi
fun iya, tabi fun ọmọkọnrin, tabi fun ọmọ-
birin, fun arakọnrin, tabi fun arabirin ti
kò ti ni ọkọ, nwọn le sọ ara wọn di aimọ́.
26 Ati lẹhin iwẹnumọ́ rẹ̀, nwọn o si ká
ọjọ meje fun u.
27 Ati li ọjọ ti yio lọ si ibi-mimọ́, si
agbalá ti inu, lati ṣe iranṣẹ ni ibi-mimọ́, on
o rú ọrẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ni Oluwa Ọlọrun wi.
28 Ati ogún ni yio jẹ fun wọn: emi ni
ogún wọn: ẹ kì yio si fun wọn ni ini ni
Israeli: emi ni ini wọn.
29 Awọn ni yio jẹ ọrẹ ẹbọ jijẹ, ati ọrẹ
ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ọrẹ ẹbọ irekọja; ati gbogbo
ohun-egún ni Israeli, yio jẹ́ ti wọn.
30 Ati ikini ninu gbogbo akọ́so nkan

Digitized by Google

gbogbo, olukuluku ọrẹ gbogbo, ninu gbọ-
gbo ọrẹ nyin, yio jẹ ti awọn alufa: ẹ o si fi
akọ́pọ iyẹfun nyin fun alufa, ki ibukun le
bà le ile rẹ.
31 Gbogbo okú nkan, ati ohun ti a fà ya
ninu ẹiyẹ tabi ninu ẹranko, ni awọn alufa
kì yio jẹ.

## ORI 45.

PẸLUPẸLU nigbati ẹnyin ba fi ibo pín ilẹ
li ogún, ẹ o gbé ọrẹ wá fun Oluwa,
eyiti o mọ́ lati ilẹ na wá: gigùn na yio jẹ
ẹgbã le ẹgbẹrun ije ni gigùn, ati ẹgbãrun ni
ibú. Eyi yio jẹ́ mimọ́ ni gbogbo àgbegbe
rẹ̀ yika.
2 Lati inu eyi, ẽdẹgbẹta yio jẹ ti ibi-
mimọ́ ni gigùn, pẹlu ẽdẹgbẹta ni ibú, ni
igun mẹrẹrin yika; ati adọta igbọnwọ fun
igbangba rẹ̀ yika.
3 Ati ninu ìwọn yi ni iwọ o wọ̀n ẹgbã
mejila le ẹgbẹrun ni gigùn, ati ẹgbarun ni
ibú; ati ninu rẹ̀ ni ibi-mimọ́ yio wà, ibi-
mimọ́ julọ.
4 Eyi ti o mọ́ ninu ilẹ na yio jẹ ti awọn
alufa, awọn iranṣẹ ibi-mimọ́, ti yio sunmọ
lati ṣe iránṣẹ fun Oluwa: yio si jẹ àye fun
ile wọn, ati ibi-mimọ́ fun ibi-mimọ́.
5 Ati ẹgbã mejila le ẹgbẹrun ni gigun,
ati ti ẹgbãrun ni ibú, ni awọn Lefite, pẹlu
awọn iranṣẹ ile na, ni ogún yará, fun ara
wọn, ni ini.
6 Ati ini ilu na li ẹnyin o yàn ẹgbarun
ni ibú, ati ẹgba mejila le ẹgbẹrun ni gigùn,
lẹba ọrẹ ipín mimọ́ na: yio jẹ ti gbogbo ile
Israeli.
7 Ati ipín kan yio jẹ ti olori nihà kan
ati niha keji ọrẹ ipin mimọ́, ati ti ini ilu,
ti o kọju si ọrẹ ipín mimọ́, ti o si kọju si
iní ti ilu, lati iha yama si yama, ati lati
ihà gabasi si gabasi: gigùn rẹ̀ yio gbe ọkan
ninu awọn ipín, lati eti yama de eti gabasi.
8 Ni ilẹ na ni iní rẹ̀ yio wà ni Israeli:
awọn olori mi kì yio si ni awọn enia mi
lara mọ́; ati ilẹ iyokù ni nwọn o fi fun ile
Israeli gẹgẹ bi ẹyà wọn.
9 Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; Ki o to fun
nyin, ẹnyin olori Israeli: ẹ mu ìwa-ipa
irẹ́jẹ kuro, ki ẹ si mu idajọ ati ododo ṣẹ,
mu ilọ́nilọwọgbà nyin kuro lọdọ awọn enia
mi, ni Oluwa Ọlọrun wi.
10 Ki ẹnyin ki o ni ìwọn títo, ati efà
títọ, ati bati títọ.
11 Efa ati bati yio jẹ ìwọn kanna, ki
bati ba le gbà ìdamẹwa homeri, ati efa
idamẹwa homeri: iwọ̀n rẹ̀ yio jẹ gẹgẹ bi ti
homeri.
12 Ṣekeli yio si jẹ́ ogún gera: ogún
ṣekeli, ṣekeli mẹdọgbọ̀n, ṣekeli mẹdogun,
ni manẹ nyin yio jẹ.
13 Eyi ni ọrẹ ti ẹ o rú; idamẹfa efa
homeri alikama kan, ẹ o si mu idamẹfa efa
homeri barle kan wá.
14 Niti aṣẹ oróro, bati oróro, idamẹwa
bati kan, lati inu kori wá, ti o jẹ homeri
onibati mẹwa; nitori bati mẹwa ni homeri
kan:
15 Ati ọdọ-agutan kan lati inu agbo, lati
inu igba, lati inu pápa tutù Israeli; fun
ọrẹ ẹbọ jijẹ, ati fun ọrẹ ẹbọ sisun, fun ọrẹ
ẹbọ idupẹ, lati fi ṣe ètutu fun wọn, ni
Oluwa Ọlọrun wi.
16 Gbogbo enia ilẹ na ni yio mu ẹbọ yi
wá fun olori ni Israeli.
17 Ti ọmọ-alade yio jẹ́ ọrẹ ẹbọ sisun, ati
ọrẹ ẹbọ jijẹ, ati ọrẹ ẹbọ mimu, ninu asè
gbogbo, ati ni oṣù titun, ati ni awọn ọjọ
isimi, ni gbogbo ajọ ile Israeli: on o pèse
ọrẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati ọrẹ ẹbọ jijẹ, ati ọrẹ ẹbọ
sisun, ati ọrẹ ẹbọ idupẹ, lati ṣe etùtu fun
ile Israeli.
18 Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; li oṣù
ekini, li ọjọ ekini oṣù, iwọ o mu ẹgbọ̀rọ
akọ malu alailabawọn, iwọ o si fi sọ ibi-
mimọ́ di mimọ́.
19 Alufa yio si mu ninu ẹjẹ ọrẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ,
yio si fi si opó ile, ati si igun mẹrẹrin ijoko
pẹpẹ, ati si opó ẹnu-ọ̀na agbalá ti inu ile.
20 Bayi ni iwọ o si ṣe li ọjọ keje oṣù fun
olukuluku ẹniti o ṣina, ati fun òpe: ẹ o si
ṣe etùtu ile na.
21 Li oṣù ekini, li ọjọ ẹkẹrinla oṣù,
ẹnyin o ni irekọja, asè ọjọ meje: akara
aiwú ni jijẹ.
22 Ati li ọjọ na ni ọmọ-alade yio pèse
ẹgbọ̀rọ akọ malu fun ọrẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ fun ara rẹ̀
ati fun gbogbo enia ilẹ na.
23 Ati ọjọ meje àse na ni yio pèse ọrẹ
ẹbọ sisun fun Oluwa, ẹgbọ̀rọ akọ malu
meje ati àgbo meje alailabawọ́n lojojumọ
fun ọjọ meje na; ati ọmọ ewurẹ kan lojo-
jumọ fun ọrẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ.
24 Yio si pèse ọrẹ ẹbọ jijẹ ti efa kan fun
ẹgbọ̀rọ akọ malu kan, ati efa kan fun àgbo
kan, ati hini ororo kan fun efa kan.
25 Li oṣù keje, li ọjọ kẹ̃dogun oṣù, ni
yio ṣe gẹgẹ bi wọnyi ni àse ọjọ meje, gẹgẹ
bi ọrẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ, gẹgẹ bi ọrẹ ẹbọ sisun, ati
gẹgẹ bi ọrẹ ẹbọ jijẹ, ati gẹgẹ bi oróro.

## ORI 46.

BAYI li Oluwa Ọlọrun wi; Ẹnu-ọ̀na
agbala ti inu ti o kọju si gabasi yio

Digitized by Google

wà ni titì ni ọjọ mẹfa ti a fi iṣiṣẹ; ṣugbọn
ni ọjọ isimi li a o ṣi i silẹ, ati li ọjọ oṣù
titun li a o si ṣi i silẹ.
2 Olori na yio si ba ẹnu-ọ̀na ilori ti ẹnu-
ọ̀na ode wọle, yio si duro nibi opó ẹnu-ọ̀na,
awọn alufa yio si pèse ọrẹ ẹbọ sisun rẹ̀ ati
ọrẹ ẹbọ idupẹ rẹ̀, on o si ma sìn ni iloro
ẹnu-ọ̀na: yio si jade wá; a kì yio si tì ẹnu-
ọ̀na titi di aṣalẹ.
3 Enia ilẹ na yio si ma sìn ni ilẹkùn
ẹnu-ọ̀na yi niwaju Oluwa ni ọjọ isimi, ati
ni oṣù titun.
4 Ọrẹ-ẹbọ sisun ti olori na yio rú si
Oluwa ni ọjọ isimi, yio jẹ ọdọ-agutan mẹfa
alailabawọn, ati agbò kan alailabàwọn,
5 Ati ọrẹ ẹbọ jijẹ yio jẹ efà kan fun agbò
kan, ati ọrẹ-ẹbọ jijẹ fun ọdọ-agutan ẹbùn
ọwọ́ rẹ̀, ati hini ororo kan fun efa kan.
6 Ati li ọjọ oṣù titun, ẹgbọ̀rọ malũ kan
ailabawọn, ati ọdọ-agutan mẹfa, ati agbò
kan: nwọn o wà lailabàwọn.
7 Yio si pèse ọrẹ-ẹbọ jijẹ, efa fun ẹgbọ̀rọ
akọ malu kan, ati efa kan fun agbò kan,
ati fun awọn ọdọ-agutan gẹgẹ bi ọwọ́ rẹ̀ ba
ti to, ati hini ororo kan fun efa kan.
8 Nigbati olori na yio ba si wọle, ọ̀na
iloro ẹnu-ọ̀na ni yio ba wọle, yio si ba ọ̀na
rẹ̀ jade.
9 Nigbati enia ilẹ na yio ba si wà siwa-
ju Oluwa ni awọn apejọ ọ̀wọ, ẹniti o ba ba
ọ̀na ẹnu-ọ̀na ariwa wọle lati sìn, yio ba ọ̀na
ẹnu-ọ̀na gusu jade; ẹniti o ba si ba ọ̀na
ẹnu-ọ̀na gusu wọle yio si ba ọ̀na ẹnu-ọ̀na
ariwa jade; kì yio ba ọ̀na ẹnu-ọna ti o ba
wọle jade, ṣugbọn yio jade lodi keji.
10 Ati olori ti o wà lãrin wọn, nigbati
nwọn ba wọle, yio wọle; nigbati nwọn ba
si jade, yio jade.
11 Ati ninu awọn asè ati ninu awọn ajọ,
ọrẹ-ẹbọ jijẹ yio jẹ efa kan fun ẹgbọ̀rọ akọ-
malu kan, ati efa kan fun agbò kan, ati
fun awọn ọdọ-agutan ẹbùn ọwọ́ rẹ̀, ati hini
ororo kan fun efa kan.
12 Nigbati olori na yio ba si pèse ọrẹ-
ẹbọ sisun atinuwá, tabi ọrẹ-ẹbọ idupẹ ati-
nuwá fun Oluwa, ẹnikan yio si ṣi ilẹkun ti
o kọjusi gabasi fun u, yio si pèse ọrẹ-ẹbọ
sisun rẹ̀, ati ẹbọ idupẹ rẹ̀, bi o ti ṣe li ọjọ-
isimi: yio si jade; ati lẹhin ijadelọ rẹ̀
ẹnikan yio tì ilẹkun.
13 Li ojojumọ ni iwọ o pèse ọdọ-agutan
kan alailabawọn ọlọdun kan fun ọrẹ-ẹbọ
sisun fun Oluwa: iwọ o ma pèse rẹ̀ loro-
wurọ̀.
14 Iwọ o si pèse ọrẹ-ẹbọ jijẹ fun u loro-
wurọ̀, idamẹfa efa, ati idamẹfa hini ororo
kan, lati fi pò iyẹfun daradara na; ọrẹ-ẹbọ
jijẹ nigbagbogbo nipa aṣẹ lailai fun Oluwa.
15 Bayi ni nwọn o pèse ọdọ-agutan na,
ati ọrẹ-ẹbọ jijẹ na, ati ororo na, lojojumọ
fun ọrẹ-ẹbọ sisun nigbagbogbo.
16 Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi; Bi olori
na ba fi ẹbùn fun ẹnikẹni ninu awọn ọmọ
rẹ̀, ogún rẹ̀ yio jẹ ti awọn ọmọ rẹ̀; yio jẹ
ini wọn nipa ijogun.
17 Bi o ba si fi ẹbùn ninu ini rẹ̀ fun
ọkan ninu awọn iranṣẹ rẹ̀, nigbana yio jẹ
tirẹ̀ titi di ọdun omnira; yio si tun pada
di ti olori na: ṣugbọn ogún rẹ̀ yio jẹ ti
awọn ọmọ rẹ̀ fun wọn.
18 Olori na kì yio si fi ipá mu ninu ogún
awọn enia lati le wọn jade kuro ninu ini
wọn, yio fi ogún fun awọn ọmọ rẹ̀ lara ini
ti ontikalarẹ̀: ki awọn enia mi ki o má ba
tuká, olukuluku kuro ni ini rẹ̀.
19 O si mu mi kọja li abawọ̀, ti o wà
lẹba ẹnu-ọ̀na, si awọn yará mimọ́ ti awọn
alufa, ti o kọjusi ariwa: si kiyesi i, ibi
kan wà nibẹ̀ ni ihà mejeji yama.
20 O si wi fun mi pe, Eyi ni ibiti awọn
alufa yio ma sè ọrẹ irekọja ati ọrẹ ẹ̀ṣẹ, ni-
biti nwọn o ma yan ọrẹ jijẹ; ki nwọn má
ba gbe wọn jade si agbalá ode, lati sọ awọn
enia di mimọ́.
21 O si mu mi jade wá si agbalá ode, o
si mu mi kọja ni igun mẹrẹrin agbalá na;
si kiyesi i, ni olukuluku igun agbalá na ni
agbalá kan gbe wà.
22 Ni igun mẹrẹrin agbalá na, ni agbalá
ti a kànpọ ologoji igbọnwọ ni gigùn, ati
ọgbọ̀n ni ibú: awọn igun mẹrẹrin wọnyi jẹ
iwọ̀n kanna.
23 Ọwọ́ ile kan si wà yika ninu wọn,
yika awọn mẹrẹrin, a si ṣe ibudaná si abẹ
ọwọ́ na yika.
24 O si wi fun mi pe, Wọnyi ni ibi awọn
ti nsè, nibiti awọn iranṣẹ ile na yio ma se
ẹbọ awọn enia.

## ORI 47.

O SI mu mi padà wá si ilẹkun ile na; si
kiyesi i, omi ntú jade lati abẹ iloro ile
na nihà gabasi: nitori iwaju ile na wà ni
gabasi, omi si nwalẹ lati abẹ apa ọtun ile
na, ni gusu pẹpẹ
2 O si mu mi jade li ọ̀na ẹnu-ọ̀na ihà
ariwa, o si mu mi yi wá ọ̀na ode si ẹnu-ọ̀na
ode ni ọ̀na ti o kọjusi gabasi; si kiyesi i,
omi ṣàn jade lati ihà ọtun.
3 Nigbati ọkọnrin na jade sihà gabasi,
pẹlu okùn kan lọwọ rẹ̀, o si wọn ẹgbẹrun

Digitized by Google

igbọnwọ, o si mu mi là omi na ja; omi na
si de kókoṣẹ̀.
4 O tun wọ̀n ẹgbẹrun, o si mu mi là
omi na ja; omi na si de ẽkun. O si wọ̀n
ẹgbẹrun, o si mu mi là a ja; omi si de
ẹgbẹ́.
5 O si wọ̀n ẹgbẹrun; odò ti nkò le wọ́:
nitori omi ti kún, omi ilúwẹ, odò ti kò ṣe
rekọja.
6 O si wi fun mi pe, Ọmọ enia, Iwọ ri
yi? O si mu mi wá, o si mu mi pada wá si
bèbe odò na.
7 Nigbati mo pada, si kiyesi i, igi pupọ̀-
pupọ̀ wà ni ihà ihin ati ni ihà ọhún li eti
odò na.
8 O si wi fun mi pe, Omi wọnyi ntú
jade sihà ilẹ gabasi, nwọn si nsọkalẹ lọ si
pẹ̀tẹlẹ, nwọn si wọ̀ okun lọ: nigbati a si
mu wọn wọ̀ inu okun, a si mu omi wọn
lara dá.
9 Yio si ṣe pe, ohunkohun ti o ba wà
lãye ti nrakò, nibikibi ti odò mejeji ba de,
yio wà lãye: ọ̀pọlọpọ ẹja yio si de, nitori
omi wọnyi yio de ibẹ̀: a o si mu wọn lara
dá; ohun gbogbo yio si yè nibikibi ti odò
na ba de.
10 Yio si ṣe pe, Awọn apẹja yio duro
lori rẹ̀ lati Engedi titi de Eneglaimu;
nwọn o jẹ ibi lati nà àwọn si; ẹja wọn o
dabi iru wọn, bi ẹja okun-nla, lọpọlọpọ.
11 Ṣugbọn ibi ẹrẹ̀ rẹ̀ ati ibi irà rẹ̀ li a kì
o mu laradá; a o fi nwọn fun iyọ̀.
12 Ati lẹba odò ni eti rẹ̀, ni ihà ihin ati
ni ihà ọhun, ni gbogbo igi jijẹ yio hù, ti
ewe rẹ̀ kì yio rọ, ti eso rẹ̀ kì yio si run:
yio ma so eso titun rẹ̀ li oṣù rẹ̀, nitori omi
wọn lati ibi mimọ́ ni nwọn ti ntú jade:
eso rẹ̀ yio si jẹ fun jijẹ, ati ewe rẹ̀ fun imu-
nilaradá.
13 Bayi li Oluwa Ọlọrun wi; eyi ni yio
jẹ ãlà, ti ẹnyin o fi jogún ilẹ na fun ara
nyin fun ẹ̀ya mejila Israeli: Josefu yio ni
ipin meji.
14 Ẹnyin o si jogún rẹ̀, olukuluku bi ti
ekeji rẹ̀: eyiti mo ti gbe ọwọ́ mi sokè lati
fi i fun awọn baba nyin; ilẹ yi yio si bọ
sọdọ nyin fun ogún.
15 Eyi ni yio si jẹ ãlà ilẹ na nihà ariwa,
lati okun nla, ni ọ̀na Hetloni, bi a ti nlọ si
Sedadi;
16 Hamati, Berota, Sibraimu, ti o wà
lãrin ãlà Damasku, ati ãlà Hamati; Hasar-
hatikonu, ti o wà ni agbègbe Haurani.
17 Alà lati okun yio si jẹ Hasar-enani,
ãlà Damasku, ati ariwa nihà ariwa, ati ãlà
Hamati. Eyi si ni ihà ariwa.
18 Ati ni ihà gabasi ẹ o wọ̀n lati ãrin
Haurani, ati lati ãrin Damasku, ati lati
ãrin Gileadi, ati lati ãrin ilẹ Israeli lẹba
Jordani, lati ãlà titi de okun gabasi. Eyi
ni ihà gabasi.
19 Ati ihà gusu si gusu, lati Tamari titi
de omi ijà ni Kadeṣi, pẹ̀tẹlẹ si okun nla.
Eyi ni ihà gusu.
20 Ihà yama pẹlu yio jẹ okun nla lati
ãlà bi a ti nlọ si Hamati. Eyi ni ihà yama.
21 Bayi li ẹ o pin ilẹ yi fun ara nyin
gẹgẹ bi awọn ẹ̀ya Israeli.
22 Yio si ṣe pe, ìbo ni ẹ o fi pin i ni
ogún fun ara nyin, ati fun awọn alejo ti o
ṣe atipo lãrin nyin, ti nwọn bi ọmọ lãrin
nyin: nwọn o si ri si nyin bi ibilẹ ninu
awọn ọmọ Israeli; nwọn o ba nyin pin i li
ogún lãrin awọn ẹ̀ya Israeli.
23 Yio si ṣe pe, ni ẹ̀ya ti alejò ba ṣe
atipo, nibẹ̀ li ẹ o fun u ni ogún, ni Oluwa
Ọlọrun wi.

## ORI 48.

WỌNYI si ni orukọ awọn ẹ̀ya na. Lati
opin ariwa titi de ọwọ́ ọ̀na Hetlonu,
bi a ba nlọ si Hamati, Hasaenani, leti
Damasku niha ariwa, de ọwọ́ Hamati;
wọnyi sa ni ihà rẹ̀ ni gabasi ati yama; ipin
kan fun Dani.
2 Ati ni àgbegbe Dani, lati ihà gabasi,
de ihà yama, ipin kan, fun Aṣeri.
3 Ati ni àgbegbe Aṣeri, lati ihà gabasi,
ani titi de ihà yama, ipin kan, fun Naftali.
4 Ati ni àgbegbe Naftali, lati ihà gaba-
si, de ihà yama, ipin kan, fun Manasse.
5 Ati ni àgbegbe Manasse, lati ihà gaba-
si, de ihà yama, ipin kan, fun Efraimu.
6 Ati ni àgbegbe Efraimu, lati ihà gaba-
si, ani titi de ihà yama, ipin kan, fun
Reubeni.
7 Ati ni àgbegbe Reubeni, lati ihà ga-
basi, ani titi de ihà yama, ipin kan, fun
Juda.
8 Ati ni àgbegbe Juda, lati ihà gabasi,
de ihà yama ni yio jẹ ọrẹ ti ẹnyin o ta,
ẹgbã-mejila, o le ẹgbẹrun ijẹ ni ibú, ati ni
gigùn, bi ọkan ninu awọn ipin iyokù, lati
ihà gabasi, de ihà yama: ibi mimọ́ yio si
wà lãrin rẹ̀.
9 Ọrẹ ti ẹnyin o si ta fun Oluwa yio jẹ
ẹgbã-mejila, o le ẹgbẹrun ni gigùn, ati
ẹgbã-marun ni ibú.
10 Ati fun wọn, ani fun awọn alufa, ni
ọrẹ mimọ́ yi yio jẹ; ni ihà ariwa, ẹgbã-
mejila, o le ẹgbẹrun ni gigùn, ati ni ihà
yama, ẹgbã-marun ni ibú, ati ni ihà gabasi,

Digitized by Google

ẹgbã-marun ni ibú, ati ni ihà gusu, ẹgbã-mejila, o-le ẹgbẹrun ni gigùn: ibi mimọ́ yio si wà lãrin rẹ̀.

11 Yio jẹ ti awọn alufa ti a yà si mimọ̀, ninu awọn ọmọ Sadoku; ti nwọn ti pa ilàna mi mọ, ti nwọn kò si ṣina ni iṣina awọn ọmọ Israeli, bi awọn Lefite ti ṣina.

12 Ọrẹ ilẹ ti a si ta yi, yio jẹ ohun mimọ́ julọ fun wọn li àgbegbe awọn Lefite.

13 Ati ni ikọjusi àgbegbe awọn alufa, ni awọn Lefite yio ni ẹgbã-mejila, o le ẹgbẹrun ni gigùn, ati ẹgbã-marun ni ibú: gigùn gbogbo rẹ̀ yio jẹ ẹgbã-mejila o le ẹgbẹrun, ati ibú rẹ̀, ẹgbã-marun.

14 Nwọn kì yio si tà ninu rẹ̀, nwọn kì yio si fi ṣe paṣiparọ, bẹ̃ni nwọn kì yio si fi akọ́so ilẹ na si ọwọ́ ẹlomiran, nitoripe o jẹ mimọ́ fun Oluwa.

15 Ati ẹgbẹ̃dọgbọn ti o kù ni ibú, ni ikọjusi ẹgbã-mejila o le ẹgbẹrun na, yio jẹ ibi aimọ́ fun ilu-nla na, fun ibugbe, ati fun àgbegbe: ilu-nla na yio si wà lãrin rẹ̀.

16 Wọnyi ni yio si jẹ iwọ̀n rẹ̀; ni ihà ariwa, ẹgbã-meji o le ẹ̃dẹgbẹta, ati ni ihà gusu, ẹgbã-meji o le ẹ̃dẹgbẹta, ati ni ihà gabasi, ẹgbã-meji o le ẹ̃dẹgbẹta, ati ni ihà yama, ẹgbã-meji o le ẹ̃dẹgbẹta.

17 Awọn àgbegbe ilu-nla na yio jẹ niha ariwa, ãdọtalerugba, ati nihà gusu, àdọtalerugba ati nihà gabasi, ãdọtalerugba, ati nihà yama ãdọtalerugba.

18 Ati iyokù ni gigùn, ni ikọjusi ọrẹ ti ipin mimọ́ na, yio si jẹ ẹgbã-marun nihà gabasi, ati ẹgbã-marun nihà yama: yio si wà ni ikọjusi ọrẹ ipin mimọ́ na, ati ibisi rẹ̀ yio jẹ fun onjẹ fun awọn ti nsìn ni ilu-nla na.

19 Awọn ti mba nsìn ilu-nla na yio si ma sìn i, lati inu gbogbo ẹ̀ya Israeli.

20 Gbogbo ọrẹ na yio jẹ ẹgbã-mejila o le ẹgbẹrun, nipa ẹgbã-mejila o le ẹgbẹrun: ẹ o si ta ọrẹ mimọ́ na, igun mẹrẹrin lọgbọ̃gba pẹlu ini ilu-nla na.

21 Ati iyokù yio jẹ ti olori, ni ihà kan, ati nihà keji ti ọrẹ mimọ́ na, ati ti ini ibi nla na, ni ikọjusi ẹgbã-mejila o le ẹgbẹrun, ọrẹ ti àgbegbe gabasi, ati nihà yama ni ikọjusi ẹgbã-mejila, o le ẹgbẹrun, nihà àgbegbe yama, ni ikọjusi awọn ipin ti olori: yio si jẹ ọrẹ mimọ́ na; ibi mimọ́ ile na, yio si wà lãrin rẹ̀.

22 Ati lati ini awọn Lefite, ati lati ini ti ilu-nla na, lãrin eyiti iṣe ti olori, lãrin àgbegbe Juda, ati lãrin àgbegbe Benjamini, yio jẹ ti olori.

23 Ati fun awọn ẹ̀ya iyokù, lati ihà gabasi de ihà yama, Benjamini ipin kan.

24 Ati ni àgbegbe Benjamini, lati ihà gabasi de ihà yama, Simeoni ipin kan.

25 Ati ni àgbegbe Simeoni, lati ihà gabasi de ihà yama, Issakari ipin kan.

26 Ati ni àgbegbe Issakari, lati ihà gabasi de ihà yama, Sebuloni ipin kan.

27 Ati ni àgbegbe Sebuloni, lati ihà gabasi de ihà yama, Gadi ipin kan.

28 Ati ni àgbegbe Gadi, ni ihà gusu si gusu, àgbegbe na yio jẹ lati Tamari de omi ijà ni Kadeṣi, ati si odò, titi de okun nla.

29 Eyi ni ilẹ ti ẹnyin o fi ìbo pin ni ogún fun awọn ẹ̀ya Israeli, wọnyi si ni ipin wọn, ni Oluwa Ọlọrun wi.

30 Wọnyi si ni ibajade ti ilu-nla na lati ìha ariwa, ẹgbã-meji, o le ẹ̃dẹgbẹta oṣùwọn.

31 Awọn bode ilu-nla na yio jẹ gẹgẹ bi orukọ awọn ẹ̀ya Israeli: bodè mẹta nihà ariwa, bodè Reubeni ọkan, bodè Juda ọkan, bodè Lefi ọkan.

32 Ati ni ihà gabasi, ẹgbã-meji o le ẹ̃dẹgbẹta: ati bodè mẹta; ati bode Josefu ọkan, bode Benjamini ọkan, bodè Dani ọkan.

33 Ati ni ihà gusu, ẹgbà-meji, o le ẹ̃dẹgbẹta ìwọn: ati bodè meta; bodè Simeoni ọkan, bode Issakari ọkan, bodè Sebuloni ọkan.

34 Ni ihà yama, ẹgbã-meji o le ẹ̃dẹgbẹta, pẹlu bodè mẹta wọn: bodè Gadi ọkan, bodè Aṣeri ọkan, bodè Naftali ọkan.

35 O jẹ ẹgbã-mẹsan ìwọn yika: orukọ ilu-nla na lati ijọ na lọ yio ma jẹ, OLUWA mbẹ nibẹ̀.

Digitized by Google

## IWE WOLI

# DANIELI.

### ORI 1.

LI ọdun kẹta ijọba Jehoiakimu, ọba Juda ni Nebukadnessari, ọba Babeli, wá si Jerusalemu, o si do tì i.

2 Oluwa si fi Jehoiakimu, ọba Juda le e lọwọ, pẹlu apakan ohun-elo ile Ọlọrun, ti o kó lọ si ilẹ Ṣinari, si ile oriṣa rẹ̀: o si kó ohun-elo na wá sinu ile-iṣura oriṣa rẹ̀.

3 Ọba si wi fun Aṣpenasi, olori awọn iwẹfa rẹ̀, pe, ki o mu awọn kan wá ninu awọn ọmọ Israeli, ninu iru-ọmọ ọba, ati ti awọn ijoye;

4 Awọn ọmọ ti kò lẹgan lara, ṣugbọn awọn ti o ṣe arẹwa, ti o si ni ìmọ ninu ọgbọ́n gbogbo, ti o mọ̀ oye, ti o si ni iyè ninu, ati iru awọn ti o yẹ lati duro li ãfin ọba ati awọn ti a ba ma kọ́ ni iwe ati ede awọn ara Kaldea.

5 Ọba si pese onjẹ wọn ojojumọ ninu adidùn ọba ati ninu ọti-waini ti o nmu: ki a bọ wọn bẽ li ọdun mẹta, pe, li opin rẹ̀, ki nwọn ki o le duro niwaju ọba.

6 Njẹ ninu awọn wọnyi ni Danieli, Hananiah, Miṣaeli, ati Asariah, lati inu awọn ọmọ Juda:

7 Awọn ẹniti olori awọn iwẹfa si fi orukọ fun: bẽli o pè Danieli ni Belteṣassari, ati Hananiah ni Ṣadraki; ati Miṣaeli ni Méṣaki; ati Asariah ni Abednego.

8 Ṣugbọn Danieli pinnu rẹ̀ li ọkàn rẹ̀ pe, on kì yio fi onjẹ adidùn ọba, ati ọti-waini ti o nmu ba ara on jẹ: nitorina o bẹ̀ olori awọn iwẹfa pe, ki on má ba ba ara on jẹ.

9 Ọlọrun sa ti mu Danieli ba oju-rere ati iyọ́nu pade lọdọ olori awọn iwẹfa.

10 Olori awọn iwẹfa si wi fun Danieli pe, Mo bẹ̀ru ọba, oluwa mi, ẹniti o yàn onjẹ nyin, ati ohun mimu nyin: nitori bawo li on o ṣe ri oju nyin ki o faro jù ti awọn ọmọkọnrin ẹgbẹ nyin kanna lọ? nigbana li ẹnyin o ṣe ki emi ki o fi ori mi wewu lọdọ ọba.

11 Nigbana ni Danieli wi fun olutọju ti olori awọn iwẹfa fi ṣe oluṣọ Danieli, Hananiah, Miṣaeli, ati Asariah pe,

12 Dán awọn ọmọ-ọdọ rẹ wò, emi bẹ̀ ọ, ni ijọ mẹwa; ki o si jẹ ki nwọn ki o ma fi ẹ̀wa fun wa lati jẹ, ati omi lati mu.

13 Nigbana ni ki a wò oju wa niwaju rẹ, ati oju awọn ọmọ ti njẹ onjẹ adidùn ọba: bi iwọ ba si ti ri i si, bẹ̃ni ki o ṣe si awọn-ọmọ-ọdọ rẹ.

14 Bẽli o gbà fun wọn li ọ̀ran yi, o si dán wọn wò ni ijọ mẹwa.

15 Li opin ọjọ mẹwa, a ri oju wọn lẹwa, nwọn si sanra jù gbogbo awọn ti njẹ onjẹ adidùn ọba lọ.

16 Bẹ̃ni olutọju mu onjẹ adidùn wọn kuro, ati ọti-waini ti nwọn iba mu, o si fun wọn li ẹ̀wa.

17 Bi o ṣe ti awọn ọmọ mẹrẹrin wọnyi ni, Ọlọrun fun wọn ni ìmọ ati oye ni gbogbo iwe ati ọgbọ́n; Danieli si li oye ni gbogbo iran ati alá.

18 Nigbati o si di opin ọjọ ti ọba ti da pe ki a mu wọn wá, nigbana ni olori awọn iwẹfa mu wọn wá siwaju Nebukadnessari.

19 Ọba si ba wọn sọ̀rọ: ninu gbogbo wọn, kò si si ẹniti o dabi Danieli, Hananiah, Miṣaeli ati Asariah: nitorina ni nwọn fi nduro niwaju ọba.

20 Ati ninu gbogbo ọ̀ran ọgbọ́n ati oye, ti ọba mbère lọwọ wọn, o ri pe ni iwọn igba mẹwa, nwọn sàn jù gbogbo awọn amoye ati ọlọgbọ́n ti o wà ni gbogbo ilẹ ijọba rẹ̀ lọ.

21 Danieli si wà sibẹ titi di ọdun ikini ti Kirusi, ọba.

### ORI 2.

ATI li ọdun keji ijọba Nebukadnessari, Nebukadnessari lá alá nipa eyi ti ọkàn rẹ̀ kò fi le ilẹ ninu rẹ̀, ti orun si dá loju rẹ̀.

2 Nigbana ni ọba paṣẹ pe, ki a pè awọn amoye ati ọlọgbọ́n, ati awọn oṣó, ati awọn Kaldea wá, lati fi alá ọba na hàn fun u. Bẹ̃ni nwọn si duro niwaju ọba.

3 Ọba si wi fun wọn pe, mo lá alá kan, ọkàn mi kò si le ilẹ lati mọ̀ alá na.

4 Nigbana ni awọn Kaldea wi fun ọba li ede awọn ara Siria pe, Ki ọba ki o pẹ́: rọ́



Digitized by Google

alá na fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ, awa o si fi
itumọ̀ na hàn.
5 Ọba dahùn o si wi fun awon Kaldea
pe, ohun na ti kuro li ori mi: bi ẹnyin kò
ba fi alá na hàn fun mi ati itumọ̀ rẹ̀ pẹlu,
a o ké nyin wẹwẹ, a o si sọ ile nyin di
ãtàn.
6 Ṣugbọn bi ẹnyin ba fi alá na hàn, ati
itumọ̀ rẹ̀ pẹlu, ẹnyin o gba ẹ̀bun ati ọrẹ ati
ọlá nla li ọwọ mi: nitorina, ẹ fi alá na hàn
fun mi, ati itumọ̀ rẹ̀ pẹlu.
7 Nwọn tun dahùn nwọn si wipe, Ki
ọba ki o rọ alá na fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀,
awa o si fi itumọ̀ rẹ̀ hàn.
8 Ọba si dahùn o wi pe, emi mọ̀ daju-
daju pe, ẹnyin fẹ mu akoko pẹ, nitoriti
ẹnyin ri pe nkan na lọ li ori mi.
9 Ṣugbọn bi ẹnyin kò ba fi alá na hàn
fun mi, njẹ ipinnu kan li ẹnyin ti ṣe: ni-
toriti ẹnyin mura lati ma sọ̀rọ eke ati idi-
bajẹ niwaju mi, titi akoko yio fi kọja:
nitorina ẹ rọ́ alá na fun mi emi o si mọ̀ pe
ẹnyin o le fi itumọ̀ rẹ̀ hàn fun mi pẹlu.
10 Awọn Kaldea si dahùn niwaju ọba,
nwọn si wipe, kò si ẹnikan ti o wà li aiye
ti o le fi ọ̀ran ọba hàn: kò si si ọba, oluwa,
tabi ijoye kan ti o bère iru nkan bẽ lọwọ
amoye, tabi ọlọgbọ́n, tabi Kaldea kan ri.
11 Ohun ti o tilẹ ṣọwọ́n ni ọba bère, kò
si si ẹlomiran ti o le fi i hàn niwaju ọba
bikoṣe awọn oriṣa, ibugbe ẹniti kì iṣe ninu
ẹran-ara.
12 Nitori ọ̀ran yi ni inu ọba fi bajẹ, o
si binu gidigidi, o si paṣẹ pe ki nwọn ki o
pa gbogbo awọn amoye Babeli run.
13 Nigbana ni aṣẹ jade lọ pe, ki nwọn
ki o pa awọn amoye; nwọn si nwá Danieli
pẹlu awọn ẹgbẹ́ rẹ̀ lati pa wọn.
14 Nigbana ni Danieli fi ìmọ ati ọgbọ́n
dahùn wi fun Arioku, ti iṣe balogun ẹṣọ
ọba, ẹniti nlọ pa awọn amoye Babeli.
15 O dahùn o si wi fun Arioku, balogun
ọba pe, Ẽṣe ti aṣẹ fi yá kánkán lati ọdọ
ọba wá bẽ? Nigbana ni Arioku fi nkan na
hàn fun Danieli.
16 Nigbana ni Danieli wọle lọ, o si bère
lọwọ ọba pe, ki o fi akokò fun on, o si
wipe, on o fi itumọ rẹ̀ hàn fun ọba.
17 Nigbana ni Danieli lọ si ile rẹ̀, o si
fi nkan na hàn fun Hananiah, Miṣaeli, ati
Asariah, awọn ẹgbẹ́ rẹ̀.
18 Pe, ki nwọn ki o bère ãnu lọwọ Ọlọ-
run, Oluwa ọrun, nitori aṣiri yi: ki Danieli
ati awọn ẹgbẹ rẹ̀ má ba ṣegbe pẹlu awọn
ọlọgbọ́n Babeli iyokù, ti o wà ni Babeli.
19 Nigbana ni a fi aṣiri na hàn fun
Danieli ni iran li oru, Danieli si fi ibukún
fun Ọlọrun, Oluwa ọrun.
20 Danieli dahùn o si wipe, Olubukún
ni orukọ Ọlọrun titi lai; nitori tirẹ̀ li
ọgbọ́n ati agbara.
21 O si nyi ìgba ati akokò pada: o nmu
ọba kuro, o si ngbe ọba leke: o si nfi ọgbọ́n
fun awọn ọlọgbọ́n, ati ìmọ fun awọn ti o
mọ̀ oye:
22 O fi ohun ijinlẹ ati aṣiri hàn: o mọ̀
ohun ti o wà li òkunkun, lọdọ rẹ̀ ni imọlẹ
si wà.
23 Mo dupẹ lọwọ rẹ, mo si fi iyìn fun ọ,
iwọ Ọlọrun awọn baba mi, ẹniti o fi ọgbọ́n
ati agbara fun mi, ti o si fi ohun ti awa
bère lọwọ rẹ hàn fun mi nisisiyi: nitoriti
iwọ fi ọ̀ran ọba hàn fun wa nisisiyi.
24 Nigbana ni Danieli wọle tọ Arioku
lọ, ẹniti ọba yàn lati pa awọn ọlọgbọ́n
Babeli run, o si lọ, o si wi fun u bayi pe;
Máṣe pa awọn ọlọgbọ́n Babeli run: mu mi
lọ siwaju ọba, emi o si fi itumọ na hàn fun
ọba.
25 Nigbana li Arioku yara mu Danieli
lọ siwaju ọba, o si wi bayi fun u pe, Mo ri
ọkọnrin kan ninu awọn ọmọ igbekun Juda,
ẹniti yio fi itumọ na hàn fun ọba.
26 Ọba dahùn o si wi fun Danieli, orukọ
ẹniti ijẹ Belteṣassari pe, Iwọ le fi alá ti mo
la hàn fun mi, ati itumọ rẹ̀ pẹlu?
27 Danieli si dahùn niwaju ọba, o si
wipe, Aṣiri ti ọba mbère, awọn ọlọgbọ́n,
awọn oṣó, awọn amoye, ati awọn alafọṣẹ, kò
le fi hàn fun ọba.
28 Ṣugbọn Ọlọrun kan mbẹ li ọrun ti o
nfi aṣiri hàn, ẹniti o si fi hàn fun Nebu-
kadnessari ohun ti mbọ wá ṣe ni ikẹhin
ọjọ. Alá rẹ, ati iran ori rẹ lori akete rẹ,
ni wọnyi;
29 Ọba, iwọ nronu lori akete rẹ, ohun
ti yio ṣe lẹhin ọla, ati ẹniti o nfi aṣiri hàn
funni mu ọ mọ̀ ohun ti mbọ wá ṣe.
30 Ṣugbọn bi o ṣe temi ni, a kò fi aṣiri
yi hàn fun mi nitori ọgbọ́n ti emi ni jù
ẹni alãye kan lọ, ṣugbọn nitori ki a le fi
itumọ na hàn fun ọba, ati ki iwọ ki o le
mọ̀ ìro ọkàn rẹ.
31 Iwọ ọba nwò, si kiyesi, ere nla kan.
Ere giga yi, ti didan rẹ̀ pọ̀ gidigidi, o duro
niwaju rẹ, ìrí rẹ̀ si ba ni lẹru gidigidi.
32 Eyi ni ere na; ori rẹ̀ jẹ wura dara-
dara, aiya ati apa rẹ̀ jẹ fadaka, inu ati
ẹ̀gbẹ rẹ̀ jẹ idẹ,
33 Itan rẹ̀ jẹ irin, ẹsẹ rẹ̀ si jọ apakan
irin, apakan amọ̀.
34 Iwọ ri titi okuta kan fi wá laisi ọwọ,

Digitized by Google

o si kọlu ere na lẹsẹ rẹ̀, ti ìṣe ti irin ati
amọ̀, o si fọ́ wọn tũtu.
35 Nigbana li a si fọ irin, amọ̀, idẹ,
fadaka ati wura pọ̀ tũtu, o si dabi iyangbo
ipaka nigba ẹ̀run; afẹfẹ si gbá wọn lọ, ti
a kò si ri ibi kan fun wọn mọ́: okuta ti o
si fọ ere na si di òke nla, o si kún gbogbo
aiye.
36 Eyiyi li alá na; awa o si sọ itumọ rẹ̀
pẹlu niwaju ọba.
37 Iwọ ọba, li ọba awọn ọba: nitori
Ọlọrun ọrun ti fi ijọba, agbara, ati ipá, ati
ogo fun ọ.
38 Ati nibikibi ti ọmọ enia wà, ẹranko
igbẹ ati ẹiyẹ oju-ọrun li o si fi le ọ lọwọ, o
si ti fi ọ ṣe alakoso lori gbogbo wọn. Iwọ
li ori wura yi.
39 Lẹhin-rẹ ni ijọba miran yio si dide ti
yio rẹ̀hin jù ọ, ati ijọba kẹta miran ti iṣe
ti idẹ, ti yio si ṣe alakoso lori gbogbo aiye.
40 Ijọba kẹrin yio si le bi irin; gẹgẹ bi
irin ti ifọ tũtu, ti si iṣẹgun ohun gbogbo:
ati gẹgẹ bi irin na ti o fọ gbogbo wọnyi,
bẹ̃ni yio si fọ tũtu ti yio si lọ̀ wọn kunna.
41 Ati gẹgẹ bi iwọ ti ri ẹsẹ ati ọmọkasẹ
ti o jẹ apakan amọ̀ amọkoko, ati apakan
irin, ni ijoba na yio yà si ara rẹ̀; ṣugbọn
ipá ti irin yio wà ninu rẹ̀, niwọn bi iwọ ti
ri irin ti o dapọ mọ amọ̀.
42 Gẹgẹ bi ọmọkasẹ na ti jẹ apakan irin
ati apakan amọ̀, bẹ̃li apakan ijọba na yio
lagbara, apakan yio si jẹ ohun fifọ.
43 Ati gẹgẹ bi iwọ si ti ri irin ti o dapọ
mọ amọ̀, nwọn o da ara wọn pọ mọ iru-
ọmọ enia, ṣugbọn nwọn kì yio fi ara wọn
mọ ara wọn, gẹgẹ bi irin kì ti idapọ mọ
amọ̀.
44 Li ọjọ awọn ọba wọnyi li Ọlọrun
ọrun yio gbe ijọba kan kalẹ, eyi ti a kì
yio le parun titi lai: a kì yio si fi ijọba na
le orilẹ-ède miran lọwọ, yio si fọ tutu, yio
si pa gbogbo ijọba wọnyi run, ṣugbọn on o
duro titi lailai.
45 Gẹgẹ bi iwọ si ti ri ti okuta na wá
laisi ọwọ lati òke wá, ti o si fọ irin, idẹ,
amọ̀, fadaka ati wura wọnni tutu; Ọlọrun
titobi ti fi hàn fun ọba, ohun ti mbọ wá
ṣe lẹhin ọla: otitọ si li alá na, itumọ rẹ̀ si
daju.
46 Nigbana ni Nebukadnessari, ọba,
wolẹ o si doju rẹ̀ bolẹ, o si fi ori balẹ fun
Danieli, o si paṣẹ pe ki nwọn ki o ṣe ẹbọ-
ọrẹ ati õrùn didùn fun u.
47 Ọba da Danieli lohùn, o si wipe,
Lõtọ ni, pe Ọlọrun nyin li Ọlọrun awọn
ọlọrun ati Oluwa awọn ọba, ati olufihàn
gbogbo aṣiri, nitori ti iwọ le fi aṣiri yi
hàn.
48 Nigbana li ọba sọ Danieli di ẹni-nla,
o si fun u li ẹ̀bun nla pupọ, o si fi i jẹ
olori gbogbo igberiko Babeli, ati olori oni-
tọju gbogbo awọn ọlọgbọ́n Babeli.
49 Danieli si bère lọwọ ọba, o si fi Ṣa-
draki, Meṣaki, ati Abednego jẹ olori ọ̀ran
igberiko Babeli; ṣugbọn Danieli joko li
ẹnu-ọ̀na ãfin ọba.

## ORI 3.

NEBUKADNESSARI ọba, si yá ere wura
kan, eyi ti giga rẹ̀ jẹ ọgọta igbọnwọ,
ati ibú rẹ̀ jẹ igbọnwọ mẹfa: o si gbé e kalẹ
ni pẹtẹlẹ Dura, ni igberiko Babeli.
2 Nigbana in Nebukadnessari ọba, ranṣẹ
lọ ipè awọn ọmọ-alade, awọn bãlẹ, ati
awọn balogun, awọn onidajọ, awọn oluṣọ
iṣura, awọn ìgbimọ, ati awọn ijoye, ati
gbogbo awọn olori igberiko, lati wá si iyasi-
mimọ́ ere ti Nebukadnessari ọba, gbé kalẹ.
3 Nigbana li awọn ọmọ-alade, awọn
bãlẹ, ati awọn balogun, awọn onidajọ,
awọn oluṣọ iṣura, awọn ìgbimọ, awọn ijoye,
ati gbogbo awọn olori igberiko pejọ si iyasi-
mimọ́ ere ti Nebukadnessari gbe kalẹ, nwọn
si duro niwaju ere ti Nebukadnessari gbé
kalẹ.
4 Nigbana ni akede kigbe soke pe, A pa
a laṣẹ fun nyin, ẹnyin enia, orilẹ, ati ède
gbogbo,
5 Pe, akokò ki akokò ti ẹnyin ba gbọ́
ohùn ipè, fère, duru, ìlu, orin, katè, ati
oniruru orin, ki ẹnyin wolẹ, ki ẹ si tẹriba
fun ere wura ti Nebukadnessari ọba gbé
kalẹ.
6 Ẹniti kò ba si wolẹ, ki o si tẹriba,
lojukanna li a o gbé e sọ si ãrin iná ileru ti
njo.
7 Nitorina, lakokò na nigbati gbogbo
enia gbọ́ ohùn ipè, fère, duru, ìlu, orin, ati
oniruru orin gbogbo, gbogbo enia, orilẹ,
ati ède wolẹ, nwọn si tẹriba fun ere wura
na ti Nebukadnessari ọba gbé kalẹ.
8 Lakokò na ni awọn ọkọnrin ara Kal-
dea kan wá, nwọn si fi awọn ara Juda sùn.
9 Nwọn dahùn, nwọn si wi fun Nebu-
kadnessari ọba, pe, Ki ọba ki o pẹ́.
10 Iwọ ọba ti paṣẹ pe, bi ẹnikẹni ba ti
gbọ́ ohùn ipè, fère, duru, ìlu, orin, katè, ati
oniruru orin, ki o wolẹ ki o si tẹriba fun
ere wura na.
11 Ẹnikẹni ti kò ba si wolẹ ki o tẹriba,
ki a gbé e sọ si ãrin iná ileru ti njo.
12 Awọn ara Juda kan wà, Ṣadraki,

Digitized by Google

Meşaki, ati Abednego ti iwọ fi şe olori
ọ̀ran igberiko Babeli: Ọba, awọn ọkọnrin
wọnyi kò kà ọ si, nwọn kò sìn orişa rẹ,
nwọn kò si tẹriba fun ere wura ti iwọ gbé
kalẹ.
13 Nigbana ni Nebukadnessari ọba paşẹ
ni ibinu ati irunu rẹ̀, pe, ki nwọn ki o mu
Şadraki, Meşaki, ati Abednego wá. Ni-
gbana ni a si mu awọn ọkọnrin wọnyi wá
siwaju ọba.
14 Nebukadnessari dahùn, o si wi fun
wọn pe, otitọ ha ni, Şadraki, Meşaki, ati
Abednego, pe, ẹnyin kò sìn orişa mi, ẹ kò
si tẹriba fun ere wura na ti mo gbé kalẹ?
15 Njẹ bi ẹnyin ba mura pe, li akokò ti
o wù ki o şe ti ẹnyin ba gbọ́ ohùn ipè,
fère, duru, ìlu, orin, katè, ati oniruru orin,
ti ẹ ba wolẹ ti ẹ ba si tẹriba fun ere wura
ti mo yá, yio şe gẹgẹ; şugbọn bi ẹnyin kò
ba tẹriba, a o gbé nyin ni wakati kanna
sọ si ãrin iná ileru ti njo; ta li Ọlọrun na
ti yio si gbà nyin kuro li ọwọ mi.
16 Şadraki, Meşaki, ati Abednego da-
hùn, nwọn si wi fun ọba pe, Nebukadnes-
sari, kò tọ si wa lati fi èsi kan fun ọ nitori
ọ̀ran yi.
17 Bi o ba ri bẽ, Ọlọrun wa ti awa nsìn,
le gbà wa lọwọ iná ileru na ti njo, on o si
gbà wa lọwọ rẹ, ọba.
18 Şugbọn bi bẽkọ, ki o ye ọ, ọba pe,
awa kì yio sìn orişa rẹ, bẽli awa kì yio si
tẹriba fun ere wura ti iwọ gbé kalẹ.
19 Nigbana ni Nebukadnessari kún fun
ibinu, àwọ oju' rẹ̀ si yipada si Şadraki,
Meşaki, ati Abednego: o dahùn, o si paşẹ
pe, ki nwọn ki o da iná ileru na ki õru rẹ̀
gboná niwọn igba meje jù bi a ti imu u
gboná ri lọ.
20 O si paşẹ fun awọn ọkọnrin ani awọn
alagbara julọ ninu ogun rẹ̀ pe ki nwọn ki o
di Şadraki, Meşaki, ati Abednego, ki nwọn
ki o si sọ wọn sinu iná ileru na ti njo.
21 Nigbana ni a dè awọn ọkọnrin wọnyi
ti awọn ti agbáda, şokoto, ati ibori wọn,
ati ẹwu wọn miran, a si gbé wọn sọ si ãrin
iná ileru ti njo.
22 Nitorina bi aşẹ ọba ti le to, ati bi
ileru na si ti gboná gidigidi to, ọwọ iná na
si pa awọn ọkọnrin ti o gbé Şadraki, Me-
şaki, ati Abednego lọ.
23 Şugbọn awọn ọkọnrin mẹtẹta wọnyi,
Şadraki, Meşaki, ati Abednego, şubu lulẹ
ni didè si ãrin iná ileru ti njo.
24 Nigbana ni Nebukadnessari ọba wa-
riri, o si dide duro lọgan, o dahùn, o si wi
fun awọn ìgbimọ rẹ̀ pe, awọn ọkọnrin mẹta
kọ a gbé sọ si ãrin iná ni didè? Nwọn si
dahùn wi fun ọba pe Lõtọ ni ọba.
25 O si dahùn wipe, Wò o, mo ri ọkọn-
rin mẹrin ni titu, nwọn sì nrin lãrin iná,
nwọn kò si farapa, ìrisi ẹnikẹrin si dabi ti
Ọmọ Ọlọrun.
26 Nigbana ni Nebukadnessari sunmọ
ẹnu-ọ̀na ileru na o dahùn o si wipe, Şadra-
ki, Meşaki, ati Abednego, ẹnyin iranşẹ
Ọlọrun Ọga-ogo, ẹ jade ki ẹ si wá. Ni-
gbana ni Şadraki, Meşaki, ati Abednego,
jade lati ãrin iná na wá.
27 Nigbana ni awọn ọmọ alade, bãlẹ,
balogun, ati awọn ìgbimọ ọba ti o pejọ ri
pe iná kò lagbara lara awọn ọkọnrin wọnyi,
bẽni irun ori wọn kan kò jona, bẽli aşọ wọn
kò si pada, õrùn iná kò tilẹ kọja lara wọn.
28 Nigbana ni Nebukadnessari dahùn o
si wipe, Olubukún li Ọlọrun Şadraki, Me-
şaki, ati Abednego, ẹniti o rán angeli rẹ̀ ti
o si gbà awọn iranşẹ rẹ̀ la, ti o gbẹkẹ le e,
nwọn si pa ọ̀rọ ọba dà, nwọn si fi ara wọn
jìn, ki nwọn ki o má şe sìn, tabi ki nwọn
ki o tẹriba fun orişakorişa bikoşe Ọlọrun ti
awọn tikarawọn.
29 Nitorina, emi paşẹ pe, olukulùku
enia, orilẹ, ati ède, ti o ba sọ ọ̀rọ odi si
Ọlọrun Şadraki, Meşaki, ati Abednego, a o
ke e wẹwẹ, a o si sọ ile rẹ̀ di àtan: nitori
kò si Ọlọrun miran ti o le gbà ni là bi iru
eyi.
30 Nigbana ni ọba gbé Şadraki, Meşaki,
ati Abednego leke ni igberiko Babeli.
31 Nebukadnessari ọba, si gbogbo enia,
orilẹ, ati ède, ti o ngbe gbogbo agbaiye;
ki alafia ki o ma pọ̀ si i fun nyin.
32 O tọ loju mi lati fi àmi ati işẹ-iyanu
ti Ọlọrun, Ọga-ogo, ti şe si mi hàn.
33 Ami rẹ̀ ti tobi to! agbara işẹ-iyanu
rẹ̀ ti pọ̀ to! ijọba ainipẹkun ni ijọba rẹ̀, ati
agbara ijọba rẹ̀ ati irandiran ni.

## ORI 4.

EMI Nebukadnessari wà li alafia ni ile
mi, mo si ngbilẹ li ãfin mi:
2 Mo si lá alá kan ti o dẹruba mi, ati
ìro ọkàn mi lori akete mi, ati iran ori mi
dãmu mi.
3 Nitorina ni mo şe paşẹ lati mu gbogbo
awọn ọlọgbọ́n Babeli wá niwaju mi, ki
nwọn ki o le fi itumọ alá na hàn fun mi.
4 Nigbana ni awọn amoye, ọlọgbọ́n,
awọn Kaldea, ati awọn alafọşẹ wá siwaju
mi: emi si rọ́ alá na fun wọn, şugbọn
nwọn kò le fi ìtumọ rẹ̀ hàn fun mi.
5 Şugbọn nikẹhin ni Danieli wá siwaju

Digitized by Google

mi, orukọ ẹniti ijẹ Beltesassari, gẹgẹ bi
orukọ oriṣa mi, ati ninu ẹniti ẹmi Ọlọrun
mimọ́ wà: mo si rọ́ alá na fun u pe,
6 Belteṣassari, olori awọn amoye, nitoriti
mo mọ̀ pe ẹmi Ọlọrun mimọ mbẹ ninu rẹ,
kò si si aṣiri kan ti o ṣoro fun ọ, sọ iran alá
ti mo lá fun mi, ati itumọ rẹ̀.
7 Bayi ni iran ori mi lori akete mi; mo
ri, si kiyesi i, igi kan duro li arin aiye,
giga rẹ̀ si pọ̀ gidigidi.
8 Igi na si dagba, o si lagbara, giga rẹ̀ si
kan ọrun, a si ri i titi de gbogbo opin aiye.
9 Ewe rẹ̀ lẹwa, eso rẹ̀ si pọ̀, lara rẹ̀ li
onjẹ wà fun gbogbo aiye: abẹ rẹ̀ jẹ iboji
fun awọn ẹranko igbẹ, ati lori ẹka rẹ̀ li
awọn ẹiyẹ oju-ọrun ngbe, ati lati ọdọ rẹ̀ li
a si ti mbọ gbogbo ẹran-ara.
10 Mo ri ninu iran ori mi lori akete mi,
si kiye si i, oluṣọ, ani ẹni mimọ́ kan sọkalẹ
lati ọrun wá;
11 O kigbe li ohùn rara, o si wi bayi pe,
Ke igi na lulẹ, ki o si ke awọn ẹka rẹ̀ kuro,
gbọ̀n ewe rẹ̀ danu; ki o si fọn eso rẹ̀ ka, jẹ
ki awọn ẹranko igbẹ kuro labẹ rẹ̀, ki awọn
ẹiyẹ si kuro lori ẹka rẹ̀:
12 Ṣugbọn, fi kukute gbòngbo rẹ̀ silẹ
ninu ilẹ̀, ani pẹlu ìde ninu irin ati idẹ ninu
koriko tutu igbẹ; si jẹ ki ìri ọrun sẹ̀ si i
lara, ki o si ni ipin rẹ̀ ninu koriko ilẹ aiye
pẹlu awọn ẹranko:
13 Ki a si pa aiya rẹ̀ da kuro ni ti enia,
ki a si fi aiya ẹranko fun u, ki igba meje
ki o si kọja lori rẹ̀.
14 Nipa ọ̀rọ lati ọdọ awọn oluṣọ li ọ̀ran
yi, ati aṣẹ nipa ọ̀rọ awọn ẹni mimọ́ ni;
nitori ki awọn alàye ki o le mọ̀ pe Ọga-ogo
li o nṣe olori ni ijọba enia, on a si fi fun
ẹnikẹni ti o wù u, on a si gbé onirẹ̀lẹ julọ
leke lori rẹ̀.
15 Alá yi li emi Nebukadnessari lá, njẹ
nisisiyi, iwọ Belteṣassari, sọ itumọ rẹ̀ fun
mi, bi gbogbo awọn ọlọgbọ́n ijọba mi kò ti
le fi itumọ rẹ̀ hàn fun mi: ṣugbọn iwọ le
ṣe e; nitori ẹmi Ọlọrun mimọ́ mbẹ lara rẹ.
16 Nigbana ni Danieli, ẹniti a npè ni
Belteṣassari wà ni ìwariri niwọn wakati
kan, ìro-inu rẹ̀ si dãmu rẹ̀. Ọba si dahùn
wipe, Belteṣassari, máṣe jẹ ki alá na, tabi
itumọ rẹ̀ ki o dãmu rẹ. Belteṣassari si
dahùn wipe, oluwa mi! ti awọn ẹniti o
korira rẹ li alá yi, ki itumọ rẹ̀ ki o si jẹ ti
awọn ọta rẹ.
17 Igi ti iwọ ri ti o si dagba, ti o si
lagbara, eyi ti giga rẹ̀ kan ọrun, ti a si ri i
de gbogbo aiye;
18 Eyi ti ewe rẹ̀ lẹwà, ti eso rẹ̀ si pọ̀,
ninu eyi ti onjẹ si wà fun gbogbo ẹda, labẹ
eyi ti awọn ẹranko igbẹ ngbe, lori ẹka eyi
ti awọn ẹiyẹ oju-ọrun ni ibugbe wọn.
19 Ọba, iwọ ni ẹniti o dagba, ti o si di
alagbara: nitori titobi rẹ ga o si kan ọrun,
agbara ijọba rẹ si de opin aiye.
20 Ati gẹgẹ bi ọba si ti ri oluṣọ kan ani
ẹni mimọ́ ti o sọkalẹ lati ọrun wá, ti o si
wipe, Ke igi na lulẹ, ki o si pa a run: ṣu-
gbọn fi kukute gbòngbo rẹ̀ silẹ lãye, ani ti
on ti ìde irin ati ti idẹ, ninu koriko tutu
igbẹ; ki a si jẹ ki ìri ọrun sẹ̀ si i lara, ki
ipin rẹ̀ si wà pẹlu awọn ẹranko igbẹ, titi
ìgba meje yio fi kọja lori rẹ,
21 Ọba, itumọ rẹ̀ li eyi, ati eyiyi li aṣẹ
Ọga-ogo, ti o wá sori ọba, oluwa mi:
22 Nwọn o le ọ kuro larin enia, ibugbe
rẹ yio si wà pẹlu awọn ẹranko igbẹ nwọn o
si mu ki iwọ ki o jẹ koriko bi malu, nwọn
o si mu ki ìri ọrun sẹ̀ si ọ lara, igba meje
yio si kọja lori rẹ, titi iwọ o fi mọ̀ pe Ọga-
ogo ni iṣe olori ni ijọba enia, on a si fi i fun
ẹnikẹni ti o wù u.
23 Ati gẹgẹ bi nwọn si ti paṣẹ pe ki
nwọn ki o fi kukute gbòngbo igi na silẹ,
ijọba rẹ yio jẹ tirẹ, lẹhin igbati o ba ti mọ̀
pe, ọrun ni iṣe olori.
24 Nitorina ọba, jẹ ki ìmọran mi ki o jẹ
itẹwọgba lọdọ rẹ, ki o si fi ododo ja ẹ̀ṣẹ rẹ
kuro, ati aiṣedẽde rẹ nipa fifi ãnu hàn fun
awọn talaka; bi yio le mu alafia rẹ pẹ.
25 Gbogbo eyi de ba Nebukadnessari,
ọba.
26 Lẹhin oṣu mejila, o nrin kiri lori ãfin
ijọba Babeli.
27 Ọba si dahùn, o wipe, Koṣepe eyi ni
Babeli nla, ti emi ti fi lile agbara mi kọ́ ni
ile ijọba, ati fun ogo ọlanla mi?
28 Bi ọ̀rọ na si ti wà lẹnu ọba, ohùn kan
fọ̀ lati ọrun wá, pe, Nebukadnessari, ọba,
iwọ li a sọ fun; pe, a gba ijọba kuro lọwọ
rẹ.
29 A o si le ọ kuro larin enia, ibugbe rẹ
yio si wà pẹlu awọn ẹranko igbẹ: nwọn o
si mu ọ jẹ koriko bi malu, igba meje yio si
kọja lori rẹ, titi iwọ o fi mọ̀ pe, Ọga-ogo ni
iṣe olori ninu ijọba enia, on a si fi i fun
ẹnikẹni ti o wù u.
30 Ni wakati kanna ni nkan na si ṣẹ si
Nebukadnessari, a si le e kuro larin enia, o
si jẹ koriko bi malu, a si mu ki ìri ọrun sẹ̀
si i lara, titi irun ori rẹ̀ fi kún gẹgẹ bi iyẹ
idì, ẽkana rẹ̀ si dabi ti ẹiyẹ.
31 Li opin igba na, Emi Nebukadnessa-
ri si gbè oju mi soke si ọrun, oye mi si
pada tọ̀ mi wá, emi si fi ibukún fun Ọga-

Digitized by Google

ogo, mo yìn, mo si fi ọla fun ẹniti o wà titi lailai, ẹniti agbara ijọba rẹ̀ jẹ ijọba ainipẹkun, agbara ati ijọba rẹ̀ lati irandiran.

32 Gbogbo awọn araiye li a si kà si bi ohun asan, on a si ma ṣe gẹgẹ bi o ti wù u ninu ogun ọrun, ati larin awọn araiye: kò si si ẹniti idá ọwọ rẹ̀ duro, tabi ẹniti iwi fun u pe, Kini iwọ nṣe nì?

33 Lakoko kanna oye mi pada tọ̀ mi wá; ati niti ogo ijọba mi, ọlá ati ogo didan mi si pada wá sọdọ mi: awọn ìgbimọ ati awọn ijoye mi si ṣafẹri mi; a si fi ẹsẹ mi mulẹ ninu ijọba mi, emi si ni ọlanla agbara jù ti iṣãju lọ.

34 Nisisiyi, emi Nebukadnessari yìn, mo si gbé Ọba ọrun ga, mo si fi ọlá fun u, ẹniti gbogbo iṣẹ rẹ̀ iṣe otitọ, ati gbogbo ọ̀na rẹ̀ iṣe idajọ: ati awọn ti nrìn ninu igberaga, on le rẹ̀ wọn silẹ.

## ORI 5.

BELṢASSARI, ọba se àse nla fun ẹgbẹrun awọn ijoye rẹ̀, o si nmu ọti-waini niwaju awọn ẹgbẹrun na.

2 Bi Belṣassari ti tọ́ ọti-waini na wò, o paṣẹ pe ki nwọn ki o mu ohun-elo wura, ati ti fadaka wá, eyiti Nebukadnessari baba rẹ̀, kó jade lati inu tempeli ti o wà ni Jerusalemu wá, ki ọba, ati awọn ijoye rẹ̀, awọn aya rẹ̀, ati awọn àle rẹ̀, ki o le ma muti ninu wọn.

3 Nigbana ni nwọn mu ohun-elo wura ti a ti kó jade lati inu tempeli ile Ọlọrun ti o wà ni Jerusalemu wá; ọba, ati awọn ijoye rẹ̀, awọn aya rẹ̀, ati awọn àle rẹ̀, si nmuti ninu wọn.

4 Nwọn nmu ọti-waini, nwọn si nkọrin ìyin si awọn oriṣa wura, ati ti fadaka, ti idẹ, ti irin, ti igi, ati ti okuta.

5 Ni wakati kanna ni awọn ika ọwọ enia kan jade wá, a si kọwe sara ẹfun ogiri niwaju ọpa-fitila li ãfin ọba: ọba si ri ọwọ ti o kọwe na.

6 Nigbana ni oju ọba yipada, ìro-inu rẹ̀ si dãmu rẹ̀, tobẽ ti amure ẹ̀gbẹ rẹ̀ tu, ẽkunsẹ̀ rẹ̀ mejeji si nlù ara wọn.

7 Ọba si kigbe kikan pe, ki a mu awọn amoye, awọn Kaldea, ati awọn alafọṣẹ wá. Ọba dahùn o si wi fun awọn ọlọgbọ́n Babeli pe, Ẹnikan ti o ba kà iwe yi, ti o ba si fi itumọ rẹ̀ hàn fun mi, on li a o fi aṣọ ododó wọ̀, a o si fi ẹ̀wọn wura kọ́ ọ li ọrùn, on o si jẹ ẹkẹta olori ni ijọba.

8 Nigbana ni gbogbo awọn amoye ọba wọle; ṣugbọn nwọn kò le kà iwe na, nwọn kò si le fi itumọ rẹ̀ hàn fun ọba.

9 Nigbana ni ẹ̀ru nla ba Belṣassari ọba gidigidi, oju rẹ̀ si yipada lori rẹ̀, ẹ̀ru si ba awọn ijoye rẹ̀.

10 Nitorina ni ayaba ṣe wọ ile-àse wá, nitori ọ̀ran ọba, ati ti awọn ijoye rẹ̀; ayaba dahùn o si wipe, Ki ọba ki o pẹ́: má ṣe jẹ ki ìro-inu rẹ ki o dãmu rẹ, má si jẹ ki oju rẹ ki o yipada.

11 Ọkọnrin kan mbẹ ni ijọba rẹ, lara ẹniti ẹmi Ọlọrun mimọ́ wà; ati li ọjọ baba rẹ, a ri imọlẹ, ati oye, ati ọgbọ́n gẹgẹ bi ọgbọ́n Ọlọrun lara rẹ̀: ẹniti Nebukadnessari ọba, baba rẹ, ani ọba, baba rẹ fi ṣe olori awọn amoye, ọlọgbọ́n, awọn Kaldea, ati awọn alafọṣẹ:

12 Niwọnbi ẹmi titayọ ati ìmọ, ati oye itumọ alá, oye ati já aló, ati lati ma ṣe itumọ ọ̀rọ ti o diju, gbogbo wọnyi li a ri lara Danieli na, ẹniti ọba fi orukọ Belteṣassari fun, njẹ nisisiyi jẹ ki a pè Danieli wá, on o si fi itumọ rẹ̀ hàn.

13 Nigbana ni a mu Danieli wá siwaju ọba. Ọba si dahùn o wi fun Danieli pe, Iwọ ni Danieli nì, ti iṣe ti inu awọn ọmọ igbekun Juda! awọn ẹniti ọba, baba mi kó lati ilẹ Juda wá?

14 Emi ti gburo rẹ pe ẹmi Ọlọrun mbẹ lara rẹ, ati pe, a ri imọlẹ, ati oye, ati ọgbọ́n titayọ lara rẹ,

15 Njẹ nisisiyi, a ti mu awọn amoye, ati awọn ọlọgbọ́n wá siwaju mi, ki nwọn ki o le ka iwe yi, ati lati fi itumọ rẹ̀ hàn fun mi: ṣugbọn nwọn kò le fi itumọ ọ̀ran na hàn:

16 Emi si gburo rẹ pe, iwọ le ṣe itumọ, iwọ si le tu ọ̀rọ ti o diju: njẹ nisisiyi, bi iwọ ba le ka iwe na, ti iwọ ba si le fi itumọ rẹ̀ hàn fun mi, a o wọ̀ ọ li aṣọ ododó, a o si fi ẹ̀wọn wura kọ́ ọ lọrun, a o si fi ọ jẹ olori ẹkẹta ni ijọba.

17 Nigbana ni Danieli dahùn, o si wi niwaju ọba pe, Jẹ ki ẹ̀bun rẹ gbe ọwọ rẹ, ki o si fi ẹsan rẹ fun ẹlomiran; ṣugbọn emi o ka iwe na fun ọba, emi o si fi itumọ rẹ̀ hàn fun u.

18 Iwọ ọba! Ọlọrun Ọga-ogo fi ijọba, ati ọlanla, ati ogo, ati ọlá fun Nebukadnessari, baba rẹ:

19 Ati nitori ọlanla ti o fi fun u, gbogbo enia, orilẹ, ati ède gbogbo nwariri, nwọn si mbẹ̀ru niwaju rẹ̀: ẹniti o wù u, a pa, ẹniti o si wù u, a da si lãye; ẹniti o wù u, a gbé ga; ẹniti o si wú u, a rẹ̀ silẹ.

20 Ṣugbọn nigbati ọkàn rẹ̀ gbega, ti inu rẹ̀ si le nipa igberaga, a mu u kuro lori itẹ rẹ̀, nwọn si gba ogo rẹ̀ lọwọ rẹ̀:

Digitized by Google

21 A si le e kuro lãrin awọn ọmọ enia: a si ṣe aiya rẹ̀ dabi ti ẹranko, ibugbe rẹ̀ si wà lọdọ awọn kẹtẹkẹtẹ igbẹ; nwọn si fi koriko bọ́ ọ gẹgẹ bi malu, a si mu ki ìri ọrun sẹ̀ si i lara; titi on fi mọ̀ pe Ọlọrun Ọga-ogo ni iṣe alakoso ninu ijọba enia, on a si yàn ẹnikẹni ti o wù u ṣe olori rẹ̀.

22 Ati iwọ Belṣassari, ọmọ rẹ̀, iwọ kò rẹ̀ ọkàn rẹ silẹ̀, bi iwọ si tilẹ ti mọ̀ gbogbo nkan wọnyi;

23 Ṣugbọn iwọ gbé ara rẹ ga si Oluwa ọrun, nwọn si ti mu ohun-elo ile rẹ̀ wá siwaju rẹ, iwọ ati awọn ijoye rẹ, ati awọn aya rẹ, ati awọn àle rẹ si ti nmu ọti-waini ninu wọn; iwọ si ti nkọrin iyìn si oriṣa fadaka, ati ti wura, ti idẹ, ti irin, ti igi, ati ti okuta, awọn ti kò riran, ti kò gbọran, bẽni nwọn kò si mọ̀: ṣugbọn Ọlọrun na, lọwọ ẹniti ẹmi rẹ wà, ati ti ẹniti gbogbo ọ̀na rẹ iṣe, on ni iwọ kò bu ọlá fun.

24 Nitorina ni a ṣe rán ọwọ na lati ọdọ rẹ̀ wá; ti a si fi kọ iwe yi.

25 Eyiyi si ni iwe na ti a kọ, MENE, MENE, TEKELI, PERESINI.

26 Eyi ni itumọ ohun na: MENE, Ọlọrun ti ṣirò ijọba rẹ, o si pari rẹ̀.

27 TEKELI; A ti wọ̀n ọ wò ninu òṣuwọn, iwọ kò si to.

28 PERESINI; A pin ijọba rẹ, a si fi fun awọn ara Media, ati awọn ara Persia.

29 Nigbana ni Belṣassari paṣẹ, nwọn si wọ̀ Danieli li aṣọ ododó, a si fi ẹ̀wọn wura kọ́ ọ lọrun, a si ṣe ikede niwaju rẹ̀ pe, ki a fi i ṣe olori ẹkẹta ni ijọba.

30 Loru ijọ kanna li a pa Belṣassari, ọba awọn ara Kaldea.

## ORI 6.

DARIUSI, ara Media si gba ijọba na, o si jẹ bi ẹni iwọn ọdun mejilelọgọta.

2 O ṣe didùn inu Dariusi lati fi ọgọfa arẹ bãlẹ sori ijọba na, ti yio wà lori gbogbo ijọba;

3 Ati lori awọn wọnyi ni alakoso mẹta: Danieli si jẹ ọkan ninu wọn: ki awọn arẹ bãlẹ ki o le ma jiyin fun wọn, ki ọba ki o má ṣe ni ipalara.

4 Danieli yi si bori gbogbo awọn alakoso ati arẹ bãlẹ wọnyi, nitoripe ẹmi titayọ wà lara rẹ̀: ọba si ngbiro lati fi i ṣe olori gbogbo ijọba.

5 Nigbana ni awọn alakoso, ati awọn arẹ bãlẹ nwá ọ̀na lati ba Danieli fẹfẹ niti ohun ijọba, ṣugbọn nwọn kò le ri ẹ̀fẹ́kẹfẹ tabi ẹ̀ṣẹkẹṣẹ lọwọ rẹ̀; niwọn bi on ti jẹ olododo enia tobẽ ti a kò si ri iṣina tabi ẹ̀ṣẹ kan lọwọ rẹ̀.

6 Nigbana ni awọn ọkọnrin wọnyi wipe, Awa kì yio le ri ẹ̀fẹ́kẹfẹ kan si Danieli bikoṣepe a ba ri i si i nipasẹ ofin Ọlọrun rẹ̀.

7 Nigbana ni awọn alakoso ati awọn arẹ bãlẹ wọnyi pejọ pọ̀ lẹṣẹkanna lọdọ ọba, nwọn si wi bayi pe ki Dariusi ọba, ki o pẹ́.

8 Gbogbo awọn olori alakoso ijọba, awọn bãlẹ ati awọn arẹ bãlẹ, awọn ìgbimọ, ati olori ogun jọ gbìmọ pọ̀ lati fi ofin ọba kan lelẹ ati lati paṣẹ lile kan, pe ẹnikẹni ti o ba bère nkan lọwọ Ọlọrun tabi enia kenia niwọn ọgbọ̀n ọjọ bikoṣepe lọwọ rẹ, ọba, a o gbé e sọ sinu ihò kiniun.

9 Njẹ nisisiyi, ọba, fi aṣẹ na lelẹ, ki o si fi ọwọ rẹ sinu iwe ki o máṣe yipada, gẹgẹ bi ofin awọn ara Media ati Persia, eyi ti a kò gbọdọ pada.

10 Nigbana ni Dariusi fi ọwọ sinu iwe ati aṣẹ na.

11 Nigbati Danieli si ti mọ̀ pe a kọ iwe na tan, o wọ ile rẹ̀ lọ; (a si ṣi oju ferese yara rẹ̀ silẹ siha Jerusalemu) o kunlẹ li ẽkun rẹ̀ nigba mẹta lõjọ, o gbadura, o si dupẹ niwaju Ọlọrun rẹ̀, gẹgẹ bi on ti iṣe nigba atijọ ri.

12 Nigbana ni awọn ọkọnrin wọnyi rún wọle, nwọn si ri Danieli ngbadura, o si mbẹbẹ niwaju Ọlọrun rẹ̀.

13 Nigbana ni nwọn wá, nwọn si wi niwaju ọba niti aṣẹ ọba pe, Kò ṣepe iwọ fi ọwọ sinu iwe pe, ẹnikan ti o ba bère ohunkohun lọwọ Ọlọrun tabi lọwọ enia kan niwọn ọgbọ̀n ọjọ, bikoṣe lọwọ rẹ, ọba, pe a o gbé e sọ sinu iho kiniun? Ọba si dahùn o wipe, Otitọ li ọ̀ran na, gẹgẹ bi ofin awọn ara Media ati Persia, ti a kò gbọdọ pada.

14 Nigbana ni nwọn dahùn nwọn si wi niwaju ọba pe, Danieli ọkan ninu awọn ọmọ igbekun Juda kò kà ọ si, ọba, ati aṣẹ, nitori eyi ti iwọ fi ọwọ rẹ sinu iwe, ṣugbọn o ngbadura rẹ̀ nigba mẹta lõjọ.

15 Nigbati ọba gbọ́ ọ̀rọ wọnyi, inu rẹ̀ bajẹ gidigidi o si fi ọkàn rẹ̀ si Danieli lati gbà a silẹ: o si ṣe lãlã ati gbà a silẹ titi fi di igbati õrun wọ̀.

16 Nigbana ni awọn ọkọnrin wọnyi pejọ lẹṣẹkanna lọdọ ọba, nwọn si wi fun ọba pe, Iwọ mọ̀, ọba, pe ofin awọn ara Media ati Persia ni pe: kò si aṣẹ tabi ofin ti ọba fi lelẹ ti a gbọdọ yipada.

17 Nigbana ni ọba paṣẹ, nwọn si mu Danieli wá, nwọn si gbé e sọ sinu iho kiniun. Ọba si dahùn o wi fun Danieli

Digitized by Google

pe, Ọlọrun rẹ, ẹniti iwọ nsìn laisimi, on o gbà ọ la.

18 A si yi okuta kan wá, nwọn si gbé e ka oju iho na; ọba si fi oruka edidi rẹ̀ sami si i, ati oruka edidi awọn ijoye rẹ̀, ki ohunkohun máṣe yipada nitori Danieli.

19 Nigbana ni Ọba wọ̀ ãfin rẹ̀ lọ, o si fi oru na gbàwẹ: bẽli a kò si gbé ohun-elo orin kan wá siwaju rẹ̀: orun kò si wá si oju rẹ̀.

20 Nigbana ni Ọba dide li afẹmọjumọ, o si yara kánkan lọ si ibi iho kiniun na.

21 Nigbati o si sunmọ iho na o fi ohùnrére ẹkun kigbe si Danieli: ọba dahùn o si wi fun Danieli pe, Danieli! iranṣẹ Ọlọrun alãye! Ọlọrun rẹ, ẹniti iwọ nsìn laisimi, ha le gbà ọ lọwọ awọn kiniun bi?

22 Nigbana ni Danieli wi fun ọba pe, ki ọba ki o pẹ.

23 Ọlọrun mi ti ran angeli rẹ̀, o si dì awọn kiniun na lẹnu, ti nwọn kò fi le pa mi lara: gẹgẹ bi a ti ri mi lailẹṣẹ niwaju rẹ̀; ati niwaju rẹ pẹlu, ọba, emi kò si ṣe ohun buburu kan.

24 Nigbana ni ọba yọ̀ gidigidi, o si paṣẹ pe, ki nwọn ki o fà Danieli jade kuro ninu iho. Bẽli a si fa Danieli jade kuro ninu iho, a kò si ri ipalara lara rẹ̀, nitoriti o gbà Ọlọrun rẹ̀ gbọ́.

25 Ọba si paṣẹ, pe ki a mu awọn ọkọnrin wọnni wá, ti o fi Danieli sùn, nwọn si gbé wọn sọ sinu iho kiniun, awọn, ati awọn ọmọ wọn, ati awọn aya wọn. Ki nwọn ki o to de isalẹ iho, awọn kiniun bori wọn, nwọn si fọ egungun wọn tũtu.

26 Nigbana ni Dariusi ọba kọwe si gbogbo enia, orilẹ, ati ède ti o wà ni gbogbo aiye pe, Ki alafia ki o ma bi si i fun nyin.

27 Mo paṣẹ pe, Ni gbogbo igberiko ijọba mi, ki awọn enia ki o ma warìri, ki nwọn si ma bẹ̀ru niwaju Ọlọrun Danieli, nitoripe on li Ọlọrun alãye, on si duro lailai, ati ijọba rẹ̀, eyi ti a kì yio le parun ni, ati agbara ijọba rẹ̀ yio si wà titi de opin.

28 O ngbà ni, o si nyọ ni, o si nṣe iṣẹ-ami ati iṣẹ-iyanu li ọrun ati li aiye, ẹniti o gbà Danieli là lọwọ awọn kiniun.

29 Bẹ̃ni Danieli yi si nṣe rere ni igba ijọba Dariusi, ati ni igba ijọba Kirusi, ara Persia.

## ORI 7.

LI ọdun kini Belṣassari, ọba Babeli, ni Danieli lá alá, ati iran ori rẹ̀ lori akete rẹ̀: nigbana ni o kọwe alá na, o si sọ gbogbo ọ̀rọ na.

2 Danieli dahùn, o si wipe, Mo ri ni iran mi li oru, si kiyesi i, afẹfẹ mẹrẹrin ọrun njà loju okun nla.

3 Ẹranko mẹrin nla si ti inu okun jade soke, nwọn si yatọ si ara wọn.

4 Ẹranko kini dabi kiniun, o si ni iyẹapa idì: mo si wò titi a fi fà iyẹ-apa rẹ̀ wọnni tu, a si gbé e soke kuro ni ilẹ, a mu ki o fi ẹsẹ duro bi enia, a si fi aiya enia fun u.

5 Sa si kiyesi, ẹrankọ miran, ekeji, ti o dabi ẹranko beari, o si gbé ara rẹ̀ soke li apakan, o si ni egungun-ìha meta lẹnu rẹ̀ larin ehin rẹ̀: nwọn si wi fun u bayi pe, Dide ki o si jẹ ẹran pipọ.

6 Lẹhin eyi, mo ri, si kiyesi i, ẹranko miran, gẹgẹ bi ẹkùn, ti o ni iyẹ-apa ẹiyẹ mẹrin li ẹhin rẹ̀; ẹranko na ni ori mẹrin pẹlu; a si fi agbara ijọba fun u.

7 Lẹhin eyi, mo ri ni iran oru, si kiyesi i, ẹranko kẹrin ti o buruju, ti o si lẹrù, ti o si lagbara gidigidi; o si ni ehin irin nla: o njẹ, o si nfọ tũtu, o si fi ẹsẹ rẹ̀ tẹ̀ iyokù mọlẹ: o si yatọ si gbogbo awọn ẹranko ti o ṣiwaju rẹ̀; o si ni iwo mẹwa.

8 Mo si kiyesi awọn iwo na, si wò o, iwo kekere miran kan si jade larin wọn, niwaju eyiti a fa mẹta tu ninu awọn iwo iṣaju: si kiyesi i, oju gẹgẹ bi oju enia wà lara iwo yi, ati ẹnu ti nsọ ohun nlanlà.

9 Mo si wò titi a fi sọ̀ itẹ́ wọnni kalẹ, titi Ẹni-àgba ọjọ na fi joko, aṣọ ẹniti o fún gẹgẹ bi ẹ̀gbọn owu, irun ori rẹ̀ si dabi irun agutan ti o mọ́: itẹ rẹ̀ jẹ ọwọ iná, ayikakẹkẹ rẹ̀ si jẹ jijo iná.

10 Iṣàn iná nṣẹyọ, o si ntu jade lati iwaju rẹ̀ wá; awọn ẹgbẹrun gbẹrun nṣe iranṣẹ fun u, ati awọn ẹgbẹgbarun nigba ẹgbarun duro niwaju rẹ̀: awọn onidajọ joko, a si ṣi iwe wọnni silẹ.

11 Nigbana ni mo wò nitori ohùn ọ̀rọ nla ti iwo na nsọ: mo si wò titi a fi pa ẹranko na, a si pa ara rẹ̀ run, a si sọ ọ sinu ọwọ iná ti njo.

12 Bi o ṣe ti awọn ẹranko iyokù ni, a ti gba agbara wọn kuro: nitori a ti yàn akokò ati ìgba fun wọn bi olukulùku yio ti pẹ to.

13 Mo ri ni iran oru,. si kiyesi i, ẹnikan bi Ọmọ enia wá pẹlu awọsanma ọrun, o si wá sọdọ Ẹni-àgba ọjọ na, nwọn si mu u sunmọ iwaju rẹ̀.

14 A si fi agbara ijọba fun u, ati ogo, ati ijọba, ki gbogbo enia, ati orilẹ, ati ède, ki o le ma sìn i; agbara ijọba rẹ̀ si jẹ agbara ijọba ainipẹkun, eyiti a kì yio rekọja, ati ijọba eyiti a kì yio le parun.

Digitized by Google

15 Ẹ̀mi emi Danieli si rẹwẹsi ninu ara mi, iran ori mi si mu mi dãmu.

16 Mo sunmọ ọkan ninu awọn ti o duro lapakan, mo si bi i lere otitọ gbogbo nkan wọnyi. Bẹ̃li o sọ fun mi, o si fi itumọ nkan wọnyi hàn fun mi.

17 Awọn ẹranko nla wọnyi, ti o jẹ mẹrin, li awọn ọba mẹrin ti yio dide li aiye.

18 Ṣugbọn awọn enia-mimọ́ ti Ọga-ogo julọ yio gbà ijọba, nwọn o si jogun ijọba na lai, ani titi lailai.

19 Nigbana ni mo si nfẹ imọ̀ otitọ ti ẹranko kẹrin, eyiti o yatọ si gbogbo awọn iyokù, ti o lẹrù gidigidi, eyi ti ehin rẹ̀ jẹ irin, ti ẽkanna rẹ̀ jẹ idẹ, ti njẹ, ti nfọ tũtu, ti o si nfi ẹsẹ rẹ̀ tẹ̀ iyokù mọlẹ.

20 Ati niti iwo mẹwa ti o wà li ori rẹ̀, ati omiran na ti o yọ soke, niwaju eyiti mẹta si ṣubu; ani iwo na ti o ni oju, ati ẹnu ti nsọ̀rọ ohun nlanla, eyi ti oju rẹ̀ si koro jù ti awọn ẹgbẹ rẹ̀ lọ.

21 Mo ri iwo kanna si mba awọn enia-mimọ́ jagun, o si bori wọn.

22 Titi Ẹni-àgba ọjọ nì fi de, ti a si fi idalare fun awọn enia-mimọ ti Ọga-ogo; titi akokò si fi de ti awọn enia-mimọ́ jogun ijọba na.

23 Bẹ̃li o wipe, Ẹranko kẹrin nì yio ṣe ijọba kẹrin li aiye, eyiti yio yàtọ si gbogbo ijọba miran, yio pa gbogbo aiye rẹ́, yio si tẹ̀ ẹ mọlẹ, yio si fọ ọ tũtu.

24 Ati iwo mẹwa, lati inu ijọba na wá ni ọba mẹwa yio dide: omiran kan yio si dide lẹhin wọn, on o si yàtọ si gbogbo awọn ti iṣaju, on o si bori ọba mẹta.

25 On o si ma sọ̀rọ nla si Ọga-ogo, yio si da awọn enia-mimọ́ ti Ọga-ogo lagara, yio si rò lati yi akokò ati ofin pada; a o si fi nwọn le e lọwọ titi fi di igba akokò kan, ati awọn akokò, ati idaji akokò.

26 Ṣugbọn awọn onidajọ yio joko, nwọn o si gbà agbara ijọba rẹ̀ lọwọ rẹ̀ lati fi ṣòfo, ati lati pa a run de opin.

27 Ati ijọba, ati agbara ijọba ati ipa gbogbo ijọba ni gbogbo abẹ-ọrun, li a o si fi fun enia awọn enia-mimọ ti Ọga-ogo, ijọba ẹniti iṣe ijọba ainipẹkun, ati gbogbo awọn alakoso ni yio ma sìn, ti nwọn o si ma tẹriba fun u.

28 Titi de ihinyi li opin ọ̀ran na. Bi o ṣe ti emi Danieli ni, igbero inu mi dãmu mi gidigidi, oju mi si yipada lori mi: ṣugbọn mo pa ọran na mọ́ li ọkàn mi.

ORI 8.

LI ọdun kẹta ijọba Belṣassari ọba, iran kan fi ara hàn fun mi, ani emi Danieli, lẹhin iran ti emi ri ni iṣaju.

2 Emi si ri loju iran, o si ṣe nigbati mo ri, ti mo si wà ni Ṣuṣani, li ãfin, ti o wà ni igberiko Elamu, mo si ri loju iran, mo si wà leti odò Ulai.

3 Mo si gbé oju mi soke, mo si ri, si kiye si i, àgbo kan ti o ni iwo meji duro lẹba odò na: iwo mejeji na si ga, ṣugbọn ekini ga jù ekeji lọ, eyiti o ga jù li o jade kẹhin.

4 Mo si ri àgbo na o nkàn siha iwọ-õrùn, ati si ariwa, ati si gusu; tobẹ ti gbogbo ẹranko kò fi le duro niwaju rẹ̀, bẹ̃ni kò si ẹniti o le gbani lọwọ rẹ̀: ṣugbọn o nṣe gẹgẹ bi ifẹ inu rẹ̀, o si nṣe ohun nlanla.

5 Bi mo si ti nwoye, kiyesi i, obukọ kan ti iha iwọ-õrùn jade wá sori gbogbo aiye, kò si fi ẹsẹ kan ilẹ: obukọ na si ni iwo nla kan lãrin oju rẹ̀.

6 O si tọ̀ àgbo ti o ni iwo meji na wá, eyi ti mo ti ri ti o duro lẹba odò na, o si fi irunu agbara sare si i.

7 Mo si ri i, o sunmọ ọdọ àgbo na, o si fi ikoro ibinu sare si i, o lu àgbo na bolẹ, o si ṣẹ́ iwo rẹ̀ mejeji: kò si si agbara ninu àgbo na, lati duro niwaju rẹ̀, ṣugbọn o lù u bolẹ o si tẹ̀ ẹ mọlẹ: kò si si ẹniti o le gbà àgbo na lọwọ rẹ̀.

8 Nigbana ni obukọ na nṣe ohun nla pupọpupọ, nigbati o si di alagbara tan, iwo nla na ṣẹ́; ati nipò rẹ̀ iwo mẹrin miran ti iṣe afiyesi si yọ jade si ọ̀na afẹfẹ mẹrẹrin ọrun.

9 Ati lati inu ọkan ninu wọn ni iwọ kekere kan ti jade, ti o si di alagbara gidigidi, si iha gusu, ati si iha ila-õrùn, ati si iha ilẹ ogo.

10 O si di alagbara, titi de ogun ọrun, o si bì ṣubu ninu awọn ogun ọrun, ati ninu awọn irawọ si ilẹ, o si tẹ̀ wọn mọlẹ.

11 Ani o gbé ara rẹ̀ ga titi de ọdọ olori awọn ogun na pãpa, a si ti mu ẹbọ ojujumọ kuro lọdọ rẹ̀, a si wó ibujoko ìwa-mimọ́ rẹ̀ lulẹ.

12 A si fi ogun le e lọwọ pẹlu ẹbọ ojojumọ nitori irekọja, a si ja otitọ lulẹ, o si nṣe eyi, o si nri rere.

13 Mo si gbọ́ ẹni-mimọ́ ti nsọ̀rọ; ẹni-mimọ̀ kan si wi fun ẹnikan ti nsọ̀rọ pe, Iran na niti ẹbọ ojojumọ, ati ti irekọja isọdahoro, ani lati fi ibi-mimọ́ ati ogun fun ni ni itẹmọlẹ yio ti pẹ to?

14 O si wi fun mi pe, titi fi di ọgbọn-



Digitized by Google

kanla le ọgọrun ti alẹ ti awurọ: nigbana ni
a o si yà ibi-mimọ́ si mimọ́.
15 O si ṣe ti emi, ani emi Danieli si ti ri
iran na, ti mo si nfẹ imọ̀ idi rẹ̀, si kiyesi i,
ẹnikan duro niwaju mi, gẹgẹ bi awọran
ọkọnrin.
16 Emi si gbọ́ ohùn enia kan lãrin odò
Ulai, ti o pè, ti o si wi pe, Gabrieli, mu ki
eleyi moye iran na.
17 Bẽli o si wá sibi ti mo duro: nigbati
o si de, ẹ̀ru bà mi, mo si da oju mi bolẹ:
ṣugbọn o wi fun mi pe, Kiyesi i, ọmọ enia:
nitoripe ti akokò igba ikẹhin ni iran na
iṣe.
18 Njẹ bi o ti mba mi sọrọ, mo dãmu,
mo si doju bolẹ: ṣugbọn o fi ọwọ kàn mi, o
si gbé mi dide duro si ipò mi.
19 O si wipe, kiyesi i, emi o mu ọ mọ̀
ohun ti yio ṣe ni igba ikẹhin ibinu na:
nitoripe, akokò igba ikẹhin ni eyi iṣe.
20 Agbò na ti iwọ ri ti o ni iwo meji nì,
awọn ọba Media ati Persia ni nwọn.
21 Obukọ onirun nì li ọba Hellene: iwo
nla ti o wà lãrin oju rẹ̀ mejeji li ọba ekini.
22 Njẹ bi eyini si ti ṣẹ́, ti iwo mẹrin
miran si dide duro nipò rẹ̀, ijọba mẹrin ni
yio dide ninu orilẹ-ède na, ṣugbọn kì yio
ṣe ninu agbara rẹ̀.
23 Li akokò ikẹhin ijọba wọn, nigbati
awọn oluṣe irẹkọja ba de ni kíkun, li ọba
kan yio dide, ti oju rẹ̀ buru, ti o si moye
ọ̀rọ arekereke.
24 Agbara rẹ̀ yio si le gidigidi, ṣugbọn kì
iṣe agbara ti on tikararẹ̀: on o si ma ṣe
iparun ti o yani lẹnu, yio si ma ri rere ninu
iṣẹ, yio si pa awọn alagbara ati awọn enia
ẹni-mimọ́ run.
25 Ati nipa arekereke rẹ̀ yio si mu ki iṣẹ
ẹ̀tan ṣe dẽde lọwọ rẹ̀; on o si gbè ara rẹ̀ ga
li ọkàn rẹ̀, lojiji ni yio si pa ọ̀pọlọpọ run,
yio dide si olori awọn ọmọ-alade nì; ṣu-
gbọn on o ṣẹ́ laisi ọwọ.
26 Ati iran ti alẹ ati ti owurọ ti a ti sọ,
otitọ ni; sibẹ, iwọ sé iran na mọ, nitoripe
fun ọjọ pipọ ni.
27 Arẹ̀ si mu emi Danieli, ara mi si ṣe
alaida niwọn ọjọ melokan; lẹhin na, mo
dide, mo si nṣe iṣẹ ọba; ẹ̀rù si bà mi, nitori
iran na, ṣugbọn kò si ẹni ti o fi ye mi.

## ORI 9.

LI ọdun kini Dariusi, ọmọ Ahasuerusi,
lati iru-ọmọ awọn ara Media wá, ti a
fi jọba lori ilẹ-ọba awọn ara Kaldea;
2 Li ọdun kini ijọba rẹ̀ li emi Danieli
fiyesi lati inu iwe, iye ọdun, nipa eyi ti ọ̀rọ
Oluwa tọ Jeremiah, woli wá, pe adọrin
ọdun li on o mu pé lori idahoro Jerusalemu.
3 Emi si kọju mi si Oluwa Ọlọrun lati
ma ṣafẹri nipa adura ati ẹ̀bẹ, pẹlu àwẹ,
ninu aṣọ-ọ̀fọ, ati ẽru.
4 Emi si gbadura si Oluwa Ọlọrun mi,
mo si ṣe ijẹwọ mi, mo si wipe, Oluwa, iwọ
Ọlọrun ti o tobi, ti o si li ẹ̀ru, ti npa majẹ-
mu ati ãnu mọ́ fun awọn ti o fẹ ẹ, ati fun
awọn ti o pa ofin rẹ̀ mọ́;
5 Awa ti ṣẹ̀, awa si ti nda ẹ̀ṣẹ, awa si ti
ṣe buburu gidigidi, awa si ti ṣọ̀tẹ, ani nipa
kikuro ninu ẹkọ́ rẹ, ati idajọ rẹ:
6 Bẽli awa kò si fi eti si awọn iranṣẹ rẹ,
awọn woli, ti o sọ̀rọ li orukọ rẹ fun awọn
ọba wa, awọn ọmọ-alade wa, ati awọn baba
wa, ati fun gbogbo awọn enia ilẹ wa.
7 Oluwa tirẹ li ododo, ṣugbọn ti wa ni
itiju, gẹgẹ bi o ti ri loni; fun awọn enia
Juda, ati fun awọn olugbe Jerusalemu, ati
fun gbogbo Israeli, ti o sunmọ tosi, ati awọn
ti o jina réré; ni gbogbo ilẹkilẹ, nibiti o
gbe ti le wọn rè, nitori ẹ̀ṣẹ wọn ti nwọn ti
ṣẹ̀ si ọ.
8 Oluwa, tiwa ni itiju, ti awọn ọba wa,
ati awọn olori wa, ati ti awọn baba wa,
nitori ti awa ti ṣọ̀tẹ si ọ.
9 Sibẹ ti Oluwa Ọlọrun wa li ãnu ati
idariji bi awa tilẹ ṣọ̀tẹ si i;
10 Bẽli awa kò si gbà ohùn Oluwa Ọlọ-
run wa gbọ́, lati ma rìn nipa ofin ti o gbé
kalẹ niwaju wa lati ọwọ awọn iranṣẹ rẹ̀,
awọn woli wá.
11 Bẽni gbogbo Israeli ti ṣẹ̀ si ofin rẹ,
ani nipa kikuro, ki nwọn ki o máṣe gbà
ohùn rẹ gbọ́; nitorina li a ṣe yi egún dà si
ori wa, ati ibura na ti a kọ sinu ofin Mose,
iranṣẹ Ọlọrun, nitori ti awa ti ṣẹ̀ si i.
12 On si mu ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ, eyi ti o sọ si wa,
ati si awọn onidajọ wa ti o nṣe idajọ fun
wa, nipa eyi ti o fi mu ibi nla bá wa: iru
eyi ti a kò ti iṣe si gbogbo abẹ ọrun, gẹgẹ
bi a ti ṣe sori Jerusalemu.
13 Gẹgẹ bi a ti kọ ọ ninu ofin Mose,
gbogbo ibi wọnyi wá sori wa: bẽli awa kò
si wá ojurere niwaju Oluwa, Ọlọrun wa, ki
awa ki o le yipada kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa, ki
a si moye otitọ rẹ.
14 Nitorina li Oluwa ṣe fiyesi ibi na, ti
o si mu u wá sori wa; nitoripe olododo li
Oluwa Ọlọrun wa ni gbogbo iṣẹ rẹ̀ ti o nṣe:
ṣugbọn awa kò gbà ohùn rẹ̀ gbọ́.
15 Njẹ nisisiyi, Oluwa Ọlọrun wa, iwọ
ti o ti fi ọwọ agbara mu awọn enia rẹ jade
lati Egipti wá, ti iwọ si ti gba orukọ fun

Digitized by Google

ara rẹ gẹgẹ bi o ti wà loni: awa ti ṣẹ̀, awa
si ti ṣe buburu gidigidi.
16 Oluwa, gẹgẹ bi gbogbo ododo rẹ, lõtọ,
jẹ ki ibinu ati irunu rẹ yi kuro lori Jerusa-
lemu, ilu rẹ, òke mimọ́ rẹ: nitori ẹ̀ṣẹ wa,
ati ẹ̀ṣẹ awọn baba wa ni Jerusalemu, ati
awọn enia rẹ ti di ẹ̀gan si gbogbo awọn ti o
yi wa ka.
17 Njẹ nitorina, Ọlọrun wa, gbọ́ adura
ọmọ-ọdọ rẹ, ati ẹ̀bẹ rẹ̀, ki o si mu ki oju rẹ
ki o mọlẹ si ibi-mimọ́ rẹ ti o dahoro, nitori
ti Oluwa.
18 Tẹ eti rẹ silẹ, Ọlọrun mi, ki o si gbọ́:
ṣi oju rẹ, ki o si wò idahoro wa, ati ilu ti a
nfi orukọ rẹ pè: nitoriti awa kò gbé ẹ̀bẹ
wa kalẹ niwaju rẹ nitori ododo wa, ṣugbọn
nitori ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ nla.
19 Oluwa, gbọ́, Oluwa, dariji: Oluwa,
tẹ eti rẹ silẹ ki o si ṣe; máṣe jafara, nitori ti
iwọ tikararẹ, Ọlọrun mi: nitori orukọ rẹ li
a fi npè ilu rẹ, ati awọn enia rẹ.
20 Bi emi si ti nwi, ti emi ngbadura, ati
bi emi si ti njẹwọ ẹṣẹ mi, ati ẹ̀ṣẹ Israeli
awọn enia mi, ti emi si ngbé ẹbẹ mi kalẹ
niwaju Oluwa, Ọlọrun mi, nitori òke mimọ́
Ọlọrun mi.
21 Bẹni, bi mo ti nwi lọwọ ninu adura
mi, ọkọnrin na, Gabrieli ti mo ti ri ni iran
mĩ li atetekọṣe, li a mu lati fò wá kankan,
o de ọdọ mi niwọn akokò ẹbọ aṣãlẹ.
22 O mu mi mọ̀, o si mba mi sọ̀rọ wipe,
Danieli, mo jade wá nisisiyi lati fi oye fun ọ.
23 Ni ipilẹṣẹ ẹ̀bẹ rẹ li ọ̀rọ ti jade wá,
emi si wá lati fi hàn fun ọ, nitoriti iwọ iṣe
ayanfẹ gidigidi: nitorina, moye ọ̀ran na,
ki o si kiyesi iran na.
24 Adọrin ọ̀sẹ li a pinnu sori awọn enia
rẹ, ati sori ilu mimọ́ rẹ, lati ṣe ipari irekọ-
ja, ati lati fi edidi di ẹ̀ṣẹ, ati lati ṣe ilaja
fun aiṣedẽde ati lati mu ododo ainipẹkun
wá ati lati ṣe edidi iran ati woli, ati lati fi
ororo yàn Ẹni-mimọ́ julọ nì.
25 Nitorina ki iwọ ki o mọ̀, ki o si ye ọ,
pe lati ijade lọ ọ̀rọ na lati tun Jerusalemu
ṣe, ati lati tun u kọ́, titi de igba ọmọ-alade
Ẹni-ororo na, yio jẹ ọ̀sẹ meje, ati ọ̀sẹ meji-
lelọgọta: a o si tun igboro rẹ̀ ṣe, a o mọdi
rẹ̀, ṣugbọn ni igba wahala.
26 Lẹhin ọ̀sẹ mejilelọgọta na li a o ke
Ẹni-ororo na kuro, kì yio si si ẹnikan fun
u, ati awọn enia ọmọ-alade kan ti yio wá
ni yio pa ilu na ati ibi-mimọ́ run; opin
ẹniti mbọ yio dabi ikún omi, ati ogun titi
de opin, eyi ni ipari idahoro.
27 On o si fi idi majẹmu kan mulẹ fun
ọ̀pọlọpọ niwọn ọ̀sẹ kan: ati lãrin ọ̀sẹ na ni
yio mu ki a dẹkun ẹbọ, ati ọrẹ-ẹbọ, irira
isọdahoro yio si duro lori ibi-mimọ́, titi
idajọ ti a pinnu yio túdà sori asọnidahoro.

## ORI 10.

LI ọdun kẹta Kirusi, ọba Persia, li a fi
ọ̀rọ kan hàn fun Danieli, orukọ ẹniti
ijẹ Belteṣassari; otitọ li ọ̀rọ na, ati lãla na
tobi, o si mọ̀ ọ̀rọ na, o si moye iran na.
2 Li ọjọ wọnni li emi Danieli fi ikãnu
ṣọ̀fọ li ọ̀sẹ mẹta gbako.
3 Emi kò jẹ onjẹ ti o dara, bẽni kò si si
ẹran tabi ọti-waini ti o wá si ẹnu mi, bẽli
emi kò fi ororo kùn ara mi rara, titi ọ̀sẹ
mẹta na fi pe.
4 Nigbati o di ọjọ kẹrinlelogun oṣu
kini, bi mo ti wà li eti odò nla, ti ijẹ
Hiddekeli;
5 Nigbana ni mo gbé oju mi soke, mo
wò, si kiyesi i, ọkọnrin kan ti o wọ̀ aṣọ
àla, ẹ̀gbẹ ẹniti a fi wura Ufasi daradara dì
li àmure:
6 Ara rẹ̀ pẹlu dabi okuta berili, oju rẹ̀ si
dabi manamána, ẹyinju rẹ̀ dabi iná fitila,
apa ati ẹsẹ rẹ̀ li awọ̀ ti o dabi idẹ ti a wẹ̀
dan, ohùn ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ si dabi ohùn ijọ enia
pupọ.
7 Emi Danieli nikanṣoṣo li o si ri iran
na, awọn ọkọnrin ti o si wà pẹlu mi kò ri
iran na; ṣugbọn ìwariri nlanla dà bò wọn,
tobẽ ti nwọn fi sá lọ lati fi ara wọn pamọ́.
8 Nitorina emi nikan li o kù, ti mo si ri
iran nla yi, kò si kù agbara ninu mi: ẹwà
mi si yipada lara mi di ibajẹ, emi kò si
lagbara mọ.
9 Sibẹ mo gbọ́ ohùn ọ̀rọ rẹ̀: nigbati mo
si gbọ́ ohùn ọ̀rọ rẹ̀, nigbana ni mo dãmu,
mo si wà ni idojubolẹ̀.
10 Sa si kiyesi i, ọwọ kan kàn mi, ti o
gbé mi dide lori ẽkun mi, ati lori atẹlẹwọ
mi.
11 O si wi fun mi pe, Danieli, iwọ ọkọn-
rin olufẹ gidigidi, ki oye ọ̀rọ ti mo nsọ fun
ọ ki o ye ọ, ki o si duro ni ipò rẹ: nitoripe
iwọ li a rán mi si nisisiyi. Nigbati on ti
sọ̀rọ bayi fun mi, mo dide duro ni ìwariri.
12 Nigbana ni o wi fun mi pe, má bẹ̀ru,
Danieli: lati ọjọ kini ti iwọ ti fi aiya rẹ si
lati moye, ti iwọ si npọ́n ara rẹ loju niwaju
Ọlọrun rẹ, a gbọ́ ọ̀rọ rẹ, emi si wá nitori
ọ̀rọ rẹ.
13 Ṣugbọn balogun ijọba Persia nì dè
mi li ọ̀na li ọjọ mọkanlelogun: ṣugbọn, wò
o, Mikaeli, ọkan ninu awọn olori balogun
wá lati ràn mi lọwọ: emi si di ipò mi mu
lọdọ awọn ọba Persia.

Digitized by Google

14 Nję nisisiyi, mo de lati mu ọ moye
ohun ti yio ba awọn enia rę ni ikęhin ọjọ :
nitori ti ọjọ pipọ ni iran na ișe.
15 Nigbati o si ti sọ iru ọ̀rọ bayi fun mi
tan, mo dojukọ ilę mo si yadi.
16 Si wò o, ęnikan ti jijọ rę̀ dabi ti awọn
ọmọ ęnia fi ọwọ kàn ète mi: nigbana ni
mo ya ęnu mi, mo si fọhùn, mo si wi fun
ęniti o duro tì mi pe, oluwa mi, niti iran
na, irora mi padą sinu mi, emi kò si lagba-
ra mọ.
17 Nitoripé bawo ni ọmọ-ọdọ oluwa mi
yi yio ti șe le ba oluwa mi yi sọ̀rọ? șugbọn
bi o șe temi ni, lojukanna, agbąra kò kù
ninu mi, bę̃ni kò si kù ẽmi ninu mi.
18 Nigbana ni ęnikan ti o ni aworan
enia wá o si tun fi ọwọ tọ́ mi, o si mu mi
lara le,
19 O si wipe, iwọ ọkọnrin olufę gidigidi,
má bę̀ru: alafia ni fun ọ, mu ara le, ani
mu ara le. Nigbati on ba mi sọ̀rọ, a si mu
mi lara le, mo si wipe, Ki oluwa mi ki o
ma sọ̀rọ, nitoriti iwọ ti mu mi lara le.
20 Nigbana ni o wipe, Iwọ ha mọ̀ idi
ohun ti mo tọ̀ ọ wá si? nisisiyi li emi o si
yipada lọ iba balogun Persia jà: nigbati
emi ba si jade lọ, kiyesi i, balogun Hellene
yio wá.
21 Șugbọn emi o fi eyi ti a kọ sinu iwe
otitọ hàn ọ: kò si si ęniti o ràn mi lọwọ si
awọn wọnyi, bikoșe Mikaeli balogun nyin.

## ORI 11.

PĘLUPĘLU li ọdun kini Dariusi ara
Media, emi pãpa duro lati mu u lọkàn
le, ati lati fi idi rę̀ kalę.
2 Nję nisisiyi li emi o fi otitọ hàn ọ,
Kiyesi i, ọba męta pęlu ni yio dide ni
Persia; ękęrin yio si șe ọlọ̀rọ̀ jù gbogbo
wọn lọ: ati nipa agbara rę̀ ni yio fi fi ọrọ̀
rú gbogbo wọn soke si ijọba Hellene.
3 Ọba alagbara kan yio si dide, yio si fi
agbara nla șe akoso, yio si ma șe gęgę bi
ifę inu rę̀.
4 Nigbati on ba dide tan, ijọba rę̀ yio
fọ́, a o si pin i si origun męręrin ọrun; kì
si ișe fun ọmọ rę̀, pęlupęlu kì si ișe ninu
agbara rę̀ ti on fi jọba, nitoriti a o fa ijọba
rę̀ tu, ani fun ęlomiran lęhin awọn wọnyi.
5 Ọba iha gusu yio si lagbara; șugbọn
ọkan ninu awọn balogun rę̀, on o si lagbara
jù u lọ, yio si jọba, ijọba rę̀ yio ję ijọba
nla.
6 Lęhin ọdun pipọ nwọn o si kó ara
wọn jọ pọ̀: ọmọbirin ọba gusu yio wá sọdọ
ọba ariwa, lati ba a dá majęmu: șugbọn on
kì yio le di agbara apá na mu; bę̃ni on kì
yio le duro, tabi apá rę̀: șugbọn a o fi on
silę, ati awọn ti o mu u wá, ati ęni ti o bi i,
ati ęniti nmu u lọkàn le li akokò ti o kọja.
7 Șugbọn ninu ęka gbòngbo rę̀ li ęnikan
yio dide ni ipò rę̀, ęniti yio wá pęlu ogun,
yio si wọ̀ ilu-olodi ọba ariwa, yio si ba wọn
șe, yio si bori.
8 On o si kó orișa wọn pęlu ere didà
wọn, ati ohunelo wọn daradara, ti fadaka,
ati ti wura ni igbekun lọ si Egipti: on o si
duro li ọdun melokan kuro lọdọ ọba ariwa.
9 On o si lọ si ijọba ọba gusu, șugbọn
yio yipada si ilę ontikararę̀.
10 Șugbọn awọn ọmọ rę̀ yio ru soke,
nwọn o si gbá ogun nla ọ̀pọlọpọ enia jọ;
ęnikan yio wọle wá, yio si bolę̀, yio si kọja
lọ. Nigbana ni yio pada, yio si gbé ogun
lọ si ilu olodi rę̀.
11 Ọba gusu yio si fi ibinu ru soke, yio
si jade wá ba a jà, ani, ọba ariwa na: on o
si kó enia pipọ jọ; șugbọn a o fi ọ̀pọlọpọ
na le e lọwọ.
12 Yio si kó ọ̀pọlọpọ na lọ, ọkàn rę̀ yio
si gbé soke; on o si bì ọ̀pọlọpọ ęgbãrun
enia șubu; șugbọn a kì yio fi ęsę rę̀ mulę
nipa eyi.
13 Nitoripe ọba ariwa yio si yipada, yio
si kó ọ̀pọlọpọ enia jọ ti yio pọ̀ jù ti ișaju
lọ, yio si wá lęhin ọdun melokan pęlu ogun
nla, ati ọ̀pọlọpọ ọrọ̀.
14 Li akoko wọnni li ọ̀pọlọpọ yio si dide
si ọba gusu; awọn ọlọ̀tę ninu awọn enia rę̀
yio si gbé ara wọn ga lati fi ęsę iran na
mulę pęlu: șugbọn nwọn o șubu.
15 Bę̃li ọba ariwa yio si wá, yio si mọdi,
yio si gbà ilu olodi; apá ogun ọba gusu kì
yio le duro, ati awọn ayanfę enia rę̀, bę̃ni
kì yio si agbara lati da a duro.
16 Șugbọn ęniti o tọ̀ ọ wá yio mã șe
gęgę bi ifę inu ara rę̀, kì yio si si ęniti yio
duro niwaju rę̀; on o si duro ni ilę dara-
dara nì, ti yio si fi ọwọ rę̀ parun.
17 On o si gbé oju rę̀ soke lati wọ̀ ọ nipa
agbara gbogbo ijọba rę̀, yio si ba a dá ma-
jęmu, bę̃ni yio șe; on o si fi ọmọbirin awọn
obirin fun u, lati bà a ję: șugbọn on kì
yio duro, bę̃ni kì yio si șe tirę̀.
18 Lęhin eyi, yio kọ oju rę̀ si erekușu
wọnni, yio si gbà ọ̀pọlọpọ: șugbọn balogun
kan fun ara rę̀, yio fi opin si ęgan rę̀: ati
nipò eyi, yio mu ęgan rę̀ pada wá sori ara
rę̀.
19 Nigbana ni yio si yi oju rę̀ pada si
ilu olodi ontikararę̀: șugbọn yio kọsę, yio
si șubu, a kì yio si ri i mọ.

Digitized by Google

20 Nigbana ni ẹnikan yio dide ni ipò rẹ̀
ti yio mu agbowode kan rekọja ninu ogo
ijọba (ilẹ Juda): ṣugbọn niwọn ijọ melo-
kan li a o si pa a run, kì yio ṣe nipa ibinu
tabi lojú ogun.
21 Ni ipò rẹ̀ li enia lasan kan yio dide,
ẹniti nwọn kì yio fi ọlá ọba fun: ṣugbọn
yio wá lojiji, yio si fi arekereke gbà ijọba.
22 Ogun ti mbò ni mọlẹ li a o fi bò wọn
mọlẹ niwaju rẹ̀, a o si fọ ọ tũtu, ati pẹlu
ọmọ-alade majẹmu kan.
23 Ati lẹhin igbati a ba ti ba a ṣe ipinnu
tan, yio fi ẹtan ṣiṣẹ: yio si gòke lọ, yio si
fi enia diẹ bori.
24 Yio si wọ̀ gbogbo ibi igberiko ọlọra;
yio si ṣe ohun ti awọn baba rẹ̀ kò ṣe ri,
tabi awọn baba nla rẹ̀: yio si fọn ikogun
ìfa, ati ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ ká si ãrin wọn: yio si
gbèro tẹlẹ si ilu olodi, ani titi akokò kan.
25 Yio si rú agbara ati igboya rẹ̀ soke si
ọba gusu ti on ti ogun nla; a o si rú ọba
gusu soke si ija pẹlu ogun nlanla ati ala-
gbara pipọ; ṣugbọn on kì yio le duro: ni-
tori nwọn o gba èro tẹlẹ si i.
26 Awọn ẹniti o jẹ ninu adidùn rẹ̀ ni yio
si pa a run, ogun rẹ̀ yio si tàn kalẹ; ọ̀pọlọ-
pọ ni yio si ṣubu ni pipa.
27 Ọkàn awọn ọba mejeji wọnyi ni yio
wà lati ṣe buburu, nwọn o si mã sọ̀rọ eké
lori tabilí kan, ṣugbọn kì yio jẹ rere; nito-
ripe opin yio wà li akokò ti a pinnu.
28 Nigbana ni yio pada lọ si ilẹ ontika-
rarẹ̀ ti on ti ọrọ̀ pupọ: ọkàn rẹ̀ yio si lodi
si majẹmu mimọ́ nì, yio ṣe e, yio si pada
lọ si ilẹ ontikararẹ̀.
29 Yio si pada wá li akokò ti a pinnu,
yio si wá si iha gusu; ṣugbọn kì yio ri bi
tí iṣaju, ni ikẹhin.
30 Nitoripe ọkọ̀ awọn ara Kittimu yio
tọ̀ ọ wá, nitorina ni yio ṣe dãmu, yio si
yipada, yio si ni ibinu si majẹmu mimọ́
nì; bẹ̃ni yio ṣe; ani on o yipada, yio si
tun ni idapọ pẹlu awọn ti o kọ̀ majẹmu
mimọ́ na silẹ.
31 Agbara ogun yio si duro li apa tirẹ̀,
nwọn o si sọ ibi mimọ́, ani ilu olodi na di
aimọ́, nwọn o si mu ẹbọ ojojumọ kuro,
nwọn o si gbé irira isọdahoro nì kalẹ.
32 Ati iru awọn ti nṣe buburu si majẹ-
mu nì ni yio fi ọ̀rọ ipọnni mu ṣọ̀tẹ: ṣugbọn
awọn enia ti o mọ̀ Ọlọrun yio mu ọkàn le,
nwọn o si ma ṣe iṣẹ agbara.
33 Awọn ti o moye ninu awọn enia yio
ma kọ́ ọ̀pọlọpọ: ṣugbọn nwọn o ma ti ipa
oju idà ṣubu, ati nipa iná, ati nipa igbe-
kun, ati nipa ikogun nijọmelo kan.
34 Njẹ nisisiyi, nigbati nwọn o ṣubu, a
o fi iranlọwọ diẹ ràn wọn lọwọ: ṣugbọn
ọ̀pọlọpọ ni yio fi ẹtan fi ara mọ́ wọn.
35 Awọn ẹlomiran ninu awọn ti o moye
yio si ṣubu, lati dan wọn wò, ati lati wẹ̀
wọn mọ́, ati lati sọ wọn di funfun, ani titi
fi di akokò opin: nitoripe yio wà li akokò
ti a pinnu.
36 Ọba na yio si ma ṣe gẹgẹ bi ifẹ inu
rẹ̀; on o si gbé ara rẹ̀ ga, yio si gbéra rẹ̀
ga jù gbogbo ọlọrun lọ, yio si ma sọ̀rọ ohun
iyanu si Ọlọrun awọn ọlọrun, yio si ma ṣe
rere titi a o fi pari ibinu: nitori a o mu eyi
ti a ti pinnu rẹ̀ ṣẹ.
37 Bẹ̃li on kì yio si kà Ọlọrun awọn
baba rẹ̀ si, tabi ifẹ awọn obirin, on kì yio
si kà ọlọrun kan si: nitoriti yio gbé ara rẹ̀
ga jù ẹni gbogbo lọ.
38 Ṣugbọn ni ipò rẹ̀, yio ma bu ọlá fun
ọlọrun awọn ilu olodi, ani ọlọrun kan ti
awọn baba rẹ̀ kò mọ̀ ri ni yio ma fi wura,
ati fadaka, ati okuta iyebiye, ati ohun
daradara bu ọlá fun.
39 Bẹ̃ gẹgẹ ni yio ṣe ninu ilu olodi
wọnni ti o lagbara julọ nipa iranlọwọ ọlọ-
run ajeji, ẹniti o jẹ́wọ rẹ̀ ni yio fi ogo fun,
ti yio si mu ṣe alakoso ọ̀pọlọpọ, yio si pín
ilẹ fun li ère.
40 Li akokò opin, ọba gusu yio kàn a,
ọba ariwa yio si fi kẹkẹ́, ati ẹlẹṣin, ati
ọ̀pọlọpọ ọkọ̀, kọ lu u bi afẹyika-ìji: on o
si wọ̀ ilẹ wọnni yio si bò wọn mọlẹ, yio si
rekọja.
41 Yio si wọ̀ ilẹ ologo nì pẹlu, ọ̀pọlọpọ
li a o si bì ṣubu: ṣugbọn awọn wọnyi ni
yio si bọ lọwọ rẹ̀, ani Edomu, ati Moabu,
ati olori awọn ọmọ Ammoni.
42 On o si nà ọwọ rẹ̀ jade si ilẹ wọnni
pẹlu, ilẹ Egipti kì yio si là a.
43 Ṣugbọn on o lagbara lori iṣura wura,
ati ti fadaka, ati lori gbogbo ohun daradara
ni ilẹ Egipti: ati awọn ara Libia, awọn ara
Etiopia yio si wà lẹhin rẹ̀.
44 Ṣugbọn ìhin lati ila-õrùn, ati lati
iwọ-õrùn wá yio dãmu rẹ̀: nitorina ni yio
ṣe fi ibinu nla jade lọ lati ma parun, ati
lati mu ọ̀pọlọpọ kuro patapata.
45 On o si pagọ ãfin rẹ̀ lãrin omi kọju si
òke mimọ́ ologo nì; ṣugbọn on o si de opin
rẹ̀, kì yio si si ẹniti yio ràn a lọwọ.

## ORI 12.

LI akoko na ni Mikaeli, balogun nla nì,
ti yio gbeja awọn ọmọ awọn enia rẹ
yio dide, akokò wahala yio si wà, iru eyi ti
kò ti isi ri, lati igba ti orilẹ-ède ti wà titi

Digitized by Google

fi di igba akokò yi, ati ni igba akokò na li
a o gbà awọn enia rẹ la, ani gbogbo awọn
ti a ti kọ orukọ wọn sinu iwe.
2 Ati ọ̀pọlọpọ ninu awọn ti o sùn ninu
erupẹ ilẹ ni yio ji, awọn miran si iye aini-
pẹkun, ati awọn miran si itiju ati ẹ̀gan aini-
pẹkun.
3 Awọn ọlọgbọ́n yio si ma tàn bi imọlẹ
ofurufu: awọn ti o si nyi ọ̀pọlọpọ pada si
ododo yio si ma tàn bi irawọ̀ lai ati lailai.
4 Ṣugbọn iwọ, Danieli sé ọ̀rọ na mọhun,
ki o si fi edidi di iwe na, titi fi di igba ikẹ-
hin: ọ̀pọlọpọ ni yio ma wadi rẹ̀, imọ yio
si di pupọ.
5 Nigbana ni emi Danieli wò, si kiyesi
i, awọn meji miran si duro, ọkan lapa ihín
eti odò, ati ekeji lapa ọhún eti odò.
6 Ẹnikan si wi fun ọkọnrin na ti o wọ̀
aṣọ àla ti o duro lori omi odò pe, opin
ohun iyanu wọnyi yio ti pẹ to?
7 Emi si gbọ́, ọkọnrin na ti o wọ̀ aṣọ àla,
ti o duro loju omi odò na, o gbé ọwọ ọtún
ati ọwọ òsi rẹ̀ si ọrun, o si fi Ẹniti o wà titi
lai nì bura pe, yio jẹ akokò kan, awọn ako-
kò, ati ãbọ akokò; nigbati yio si ti ṣe
aṣepe ĩfunka awọn enia mimọ́, gbogbo
nkan wọnyi li a o si pari.
8 Emi si gbọ́, sugbọn kò ye mi: nigbana
ni mo wipe, Oluwa mi, kini yio ṣẹ ikẹhin
wọnyi?
9 O si wipe, Mã ba ọ̀na rẹ lọ, Danieli,
nitoriti a ti se ọ̀rọ na mọ sọhún, a si fi edi-
di di i titi fi di igba ikẹhin.
10 Ọ̀pọlọpọ li a o wẹ̀ mọ́, nwọn o si di
funfun, a o si dan wọn wò: ṣugbọn awọn
ẹni-buburu yio ma ṣe buburu: gbogbo
awọn enia buburu kì yio kiyesi i; ṣugbọn
awọn ọlọgbọ́n ni yio kiyesi i.
11 Ati lati igba akokò ti a o mu ẹbọ
ojojumọ kuro, ati lati gbé irira isọdahoro
kalẹ, yio jẹ ẹgbẹrun ati igba le ãdọrun ọjọ.
12 Ibukún ni fun ẹniti o duro dè, ti o si
de ẹgbẹrun, ati ọ̃durun le marundilogoji
ọjọ ni.
13 Ṣugbọn iwọ ma ba ọ̀na rẹ lọ, titi opin
yio fi de, iwọ o si simi, iwọ o si dide duro
ni ipo rẹ ni ikẹhin ọjọ.

# HOSEA.

## ORI 1.

ỌRỌ Oluwa ti o tọ̀ Hosea, ọmọ Beeri wá,
li ọjọ Ussiah, Jotamu, Ahasi, ati He-
sekiah, awọn ọba Juda, ati li ọjọ Jeroboamu
ọmọ Joaṣi, ọba Israeli.
2 Ibẹ̀rẹ ọ̀rọ Oluwa si Hosea. Oluwa si
wi fun Hosea pe, Lọ, fẹ́ agbère obirin kan
fun ara rẹ, ati awọn ọmọ agbère; nitori ilẹ
yi ti ṣe agbère gidigidi, kuro lẹhin Oluwa.
3 O si lọ o si fẹ́ Gomeri ọmọbirin Dibla-
imu; ẹniti o loyún, ti o si bi ọmọkọnrin
kan fun u.
4 Oluwa si wi fun u pe, Pè orukọ rẹ̀ ni
Jesreeli; nitori niwọ̀n igbà diẹ, emi o bẹ̀
ẹ̀jẹ Jesreeli wò li ara ile Jehu, emi o si mu
ki ijọba ile Israeli kasẹ̀.
5 Yio si ṣe li ọjọ na, li emi o ṣẹ́ ọrun
Israeli ni afonifoji Jesreeli.
6 O si tún loyún, o si bi ọmọbirin kan.
Ọlọrun si wi fun u pe, Pè orukọ rẹ̀ li Loru-
hama: nitori emi kì yio tún ma ṣãnu fun
ile Israeli mọ, nitori emi o mu wọn kuro.
7 Ṣugbọn emi o ṣãnu fun ile Juda, emi o
si fi Oluwa Ọlọrun wọn gbà wọn là, emi kì
yio si fi ọrun, tabi idà, tabi ogun, ẹṣin,
tabi ẹlẹṣin gbà wọn là.
8 Nigbati o gbà ọmu li ẹnu Loruhama,
o si loyún o si bi ọmọkọnrin kan.
9 Nigbana ni Ọlọrun wipe, Pè orukọ rẹ̀
ni Loammi; nitori ẹnyin kì iṣe enia mi,
emi kì yio si ṣe Ọlọrun nyin.
10 Ṣugbọn iye awọn ọmọ Israeli yio ri
bi iyanrin okun, ti a kò le wọ̀n ti a kò si lè
ikà; yio si ṣe, ni ibi ti a gbe ti wi fun wọn
pẹ, Ẹnyin kì iṣe enia mi, ibẹ̀ li a o gbe wi
fun wọn pe, Ẹnyin li ọmọ Ọlọrun alãyè.
11 Nigbana ni a o kó awọn ọmọ Juda
ati awọn ọmọ Israeli jọ pọ̀, nwọn o si yàn
olori kan fun ara wọn, nwọn o si jade kuro
ni ilẹ na: nitori nla ni ọjọ Jesreeli yio jẹ.

Digitized by Google

ORI 2.

EWI fun awọn arakọnrin nyin, Ammi;
ati fun awọn arabirin nyin, Ruhama.
2 Ẹ ba iya nyin wijọ, ẹ wijọ; nitori on
kì iṣe aya mi, bẹ̃ni emi kì iṣe ọkọ rẹ̀: nito-
ri na jẹ ki on ki o mu gbogbo agberè rẹ̀
kuro ni iwaju rẹ̀, ati gbogbo panṣaga rẹ̀
kuro larin ọyàn rẹ̀.
3 Ki emi má ba tú u si ihòho, emi o si
gbe e kalẹ bi ọjọ ti a bi i, emi o si ṣe e bi
ijù, emi o si gbe e kalẹ bi ilẹ gbigbẹ emi o
si fi ongbẹ pa a kú.
4 Emi kì yio si ṣãnu fun awọn ọmọ rẹ̀;
nitoriti nwọn jẹ́ ọmọ agbère.
5 Nitoriti iya wọn ti hùwa agbère: ẹniti
o loyun wọn ti ṣe ohun itiju: nitori ti o
wipe, Emi o tun tọ̀ awọn ayànfẹ́ mi lẹhìn,
ti nfun mi ni onjẹ mi ati omi mi, irun
agùtan mi ati ọgbọ̀ mi, ororo mi, ati ohun
mimu mi.
6 Nitorina kiyesi i, emi o fi ẹgún sagbà-
ra yi ọ̀na rẹ̀ ka, emi o si mọ odi, ti on kì
yio fi ri ọ̀na rẹ̀ mọ.
7 On o si lepa awọn ayànfẹ́ rẹ̀, ṣugbọn
kì yio le ba wọn; on o si wá wọn, ṣugbọn
kì yio ri wọn: nigbana ni yio wipe, Emi o
padà tọ̀ ọkọ mi iṣãju lọ; nitoriti o sàn fun
mi nigbana jù ti isisiyi lọ.
8 Nitori on kò ti mọ̀ pe emi li ẹniti o
fun u li ọkà, ati ọti-waini titun, ati ororo:
ti mo si mu fàdakà ati wurà rẹ̀ pọ si i, ti
nwọn fi ṣe Baali.
9 Nitorina li emi o ṣe padà, emi o si mu
ọkà mi kuro li akokò rẹ̀, ati ọti-waini mi ni
igbà rẹ̀, emi o si gbà irun agùtan ati ọgbọ̀
mi padà, ti mo ti fi fun u lati bò ihòho rẹ̀.
10 Nisisiyi li emi o ṣi itiju rẹ̀ silẹ li oju
awọn ayànfẹ́ rẹ̀, ẹnikẹni kì yio si gbà a
lọwọ mi.
11 Emi o si mu ki gbogbo ayọ̀ rẹ̀ de
opin, ọjọ asè rẹ̀, oṣù titun rẹ̀, ati ọjọ isimi
rẹ̀, gbogbo ọjọ ọ̀wọ rẹ̀.
12 Emi o si pa ajàra rẹ̀ ati igi ọpọ̀tọ rẹ̀
run, niti awọn ti o ti wipe, Awọn wọnyi li
èrè mi ti awọn ayànfẹ́ mi ti fi fun mi; emi
o si sọ wọn di igbo, awọn ẹranko igbẹ yio
si jẹ́ wọn.
13 Emi o si bẹ̀ ọjọ́ Baalimu wò li ara rẹ̀,
ninu eyiti on fi turari joná fun wọn, ti on
si fi oruka eti, ati ohun ọ̀ṣọ rẹ̀, ṣe ara rẹ̀
lọṣọ, ti on si tọ̀ awọn ayànfẹ́ rẹ̀ lẹhìn lọ, ti
on si gbagbe mi, ni Oluwa wi.
14 Nitorina, kiyesi i, emi o tàn a, emi o
si mu u wá si aginjù, emi o si sọ̀rọ itùnu
fun u.
15 Emi o si fun u ni ọgbà àjara rẹ̀ lati
ibẹ̀ wá, ati afonifoji Akori fun ilẹ̀kun ireti:
on o si kọrin nibẹ̀, bi li ọjọ ewe rẹ̀, ati bi li
ọjọ ti o jade lati ilẹ Egipti wá.
16 Yio si ṣe li ọjọ na, iwọ o pè mi ni
Iṣi; iwọ kì yio si pè mi ni Baali mọ, ni
Oluwa wi,
17 Nitori emi o mu orukọ awọn Baali
kuro li ẹnu rẹ̀, a kì yio si fi orukọ wọn
ranti wọn mọ́.
18 Li ọjọ na li emi o si fi awọn ẹranko
igbẹ, ati ẹiyẹ oju ọrun, ati ohun ti nrakò
lori ilẹ da majẹmu fun wọn, emi o si ṣẹ́
ọrun ati idà ati ogun kuro ninu aiye, emi o
si mu wọn dubulẹ li ailewu.
19 Emi o si fẹ́ ọ fun ara mi titi lai; ni-
tõtọ, emi o si fẹ́ ọ fun ara mi ni ododo, ni
idajọ, ati ni iyọ́nu, ati ni ãnu.
20 Emi o tilẹ fẹ́ ọ fun ara mi ni otitọ,
iwọ o si mọ̀ Oluwa.
21 Yio si ṣe li ọjọ na, emi o dahùn, emi
o dá awọn ọrun li ohùn, nwọn o si da aiye
lohùn; li Oluwa wi.
22 Ilẹ yio si dá ọkà, ati ọti-waini, ati
ororo, li ohùn; nwọn o si dá Jesreeli li
ohùn.
23 Emi o si gbìn i fun ara mi lori ilẹ,
emi o si ṣãnu fun ẹniti kò ti ri ãnu gbà;
emi o si wi fun awọn ti kì iṣe enia mi pe,
Iwọ li enia mi; on o si wipe, Iwọ li Ọlọrun
mi.

ORI 3.

OLUWA si wi fun mi pe, Tun lọ, fẹ́ obi-
rin kan ti iṣe olùfẹ́ ọrẹ rẹ̀, ati panṣagà,
gẹgẹ bi ifẹ Oluwa si awọn ọmọ Israeli, ti
nwò awọn ọlọrun miràn, ti nwọn si nfẹ́
akàra eso àjara.
2 Bẹ̃ni mo rà a fun ara mi ni fadakà
mẹ̃dogun, ati homeri barli kan pẹlu ãbọ̀:
3 Mo si wi fun ọ pe, Iwọ o ba mi gbe li
ọjọ pupọ̀; iwọ kì yio si hùwa agbère, iwọ
kì yio si jẹ ti ọkọnrin miràn: bẹ̃li emi o jẹ
tirẹ pẹlu.
4 Nitori ọjọ pupọ̀ li awọn ọmọ Israeli
yio gbe li aini ọba, ati li aini olori, ati li
aini ẹbọ, li aini ere, ati li aini awò-aiyà, ati
li aini tẹrafimu.
5 Lẹhìn na awọn ọmọ Israeli yio padà,
nwọn o si wá Oluwa Ọlọrun wọn, ati Dafi-
di ọba wọn; nwọn o si bẹ̀ru Oluwa, ati ore
rẹ̀ li ọjọ ikẹhìn.

ORI 4.

EGBỌ́ ọ̀rọ Oluwa, ẹnyin ọmọ Israeli;
nitori Oluwa ni ẹjọ kan ba awọn ara

Digitized by Google

ilẹ na wi, nitoriti kò si otitọ, tabi ãnu, tabi
imọ Ọlọrun ni ilẹ na.
2 Nipa ibura, ati eke, ati ipani, ati olè,
ati iṣe panṣaga, nwọn gbijà, ẹ̀jẹ si nkàn
ẹ̀jẹ.
3 Nitorina ni ilẹ na yio ṣe ṣọ̀fọ, ati olù-
kuluku ẹniti ngbé inu rẹ̀ yio rọ, pẹlu awọn
ẹranko igbẹ, ati pẹlu awọn ẹiyẹ oju ọrun;
a o si mu awọn ẹja inu okun kuro pẹlu.
4 Ṣugbọn má jẹ ki ẹnikẹni ki o jà, tabi
ki o ba ẹnikeji rẹ̀ wi: nitori awọn enia rẹ
dabi awọn ti mba alufa jà.
5 Iwọ o si ṣubu li ọ̀san, woli yio si ṣubu
pẹlu rẹ li alẹ, emi o si ke iya rẹ kuro.
6 A ké awọn enia mi kuro nitori aini
imọ: nitori iwọ ti kọ̀ imọ silẹ, emi o si kọ̀
ọ, ti iwọ ki yio ṣe alufa mi mọ: niwọ̀n
bi iwọ ti gbagbe ofin Ọlọrun rẹ, emi pẹlu o
gbagbe awọn ọmọ rẹ.
7 Bi a ti mu wọn pọ̀ si i to, bẹ̃ na ni
nwọn si dẹ̀ṣẹ si mi to: nitorina emi o yi
ogo wọn padà si itiju.
8 Nwọn jẹ ẹ̀ṣẹ awọn enia mi, nwọn si
gbe ọkàn wọn si aiṣedẽde wọn.
9 Yio si ṣe, gẹgẹ bi enia, bẹ̃li alufa: emi
o si bẹ̀ wọn wò nitori ọ̀na wọn, emi o si san
ẹ̀rè iṣẹ wọn padà fun wọn.
10 Nwọn o si jẹ, nwọn ki o si yó: nwọn
o ṣe agbère, nwọn ki o si rẹ̀: nitori nwọn
ti fi ati-kiyesi Oluwa silẹ.
11 Agbère ati ọti-waini, ati ọti-waini
titun a ma gbà enia li ọkàn.
12 Awọn enia mi mbère imọ lọwọ igi
wọn, ọpá wọn si nfi hàn fun wọn: nitori
ẹmi agbère ti mu wọn ṣina, nwọn si ti ṣe
agbère lọ kuro labẹ Ọlọrun wọn.
13 Nwọn rubọ lori awọn oke-nla, nwọn
si sun turari lori awọn oke kékèké, labẹ
igi oaku ati igi poplari ati igi ẹlmu, nitoriti
ojiji wọn dara: nitorina awọn ọmọbirin
nyin yio ṣe agbère, ati awọn afẹ́sọnà nyin
yio ṣe panṣagà.
14 Emi ki yio ba awọn ọmọbirin nyin
wi nigbati nwọn ba ṣe agbère, tabi awọn
afẹ́sọnà nyin nigbati nwọn ba ṣe panṣagà:
nitori nwọn yà si apakan pẹlu awọn agbère,
nwọn si mba awọn panṣagà rubọ̀: nitorina
awọn enia ti kò ba moye yio ṣubu.
15 Bi iwọ, Israeli, ba ṣe agbère, máṣe jẹ
ki Juda ṣẹ̀; ẹ má si wá si Gilgali, bẹ̃ni ki
ẹ má si goke lọ si Bet-afeni, bẹ̃ni ki ẹ má
si bura pe, Oluwa mbẹ.
16 Nitori Israeli ṣe agidi bi ọmọ malu
alagidi; nisisiyi Oluwa yio bọ́ wọn bi ọdọ-
agùtan ni ibi ayè nla.
17 Efraimu dapọ̀ mọ òriṣa: jọwọ rẹ̀ si.
18 Ohun mimu wọn di kikan: nwọn ṣe
agbère gidigidi; awọn olori rẹ̀ fẹ itiju, ẹ
bun u li ayè.
19 Afẹfẹ ti dè e pẹlu mọ iyẹ́ apa rẹ̀,
nwọn o si tiju nitori ẹbọ wọn.

## ORI 5.

EGBỌ́ eyi, ẹnyin alufa: si tẹtilelẹ ẹnyin
ile Israeli; ki ẹ si gbọ́, ile ọba na;
nitori idajọ kàn nyin, nitoriti ẹnyin ti jẹ
ẹgẹ́ si Mispa, àwọn ti a nà silẹ lori Tabori.
2 Awọn ọlọ̀tẹ si jinlẹ ni pipanirun, emi
o jẹ olùbawí gbogbo wọn.
3 Emi mọ̀ Efraimu, Israeli kò si pamọ́
fun mi: nitori nisisiyi, Efraimu, iwọ ṣe
agbère, Israeli si dibajẹ.
4 Iṣe wọn ki o jọwọ wọn lati yipadà si
Ọlọrun wọn: nitori ẹmi agbère wà lãrin
wọn, nwọn kò si mọ̀ Oluwa.
5 A si rẹ̀ ogo Israeli silẹ loju ara rẹ̀;
nitorina ni Israeli ati Efraimu yio ṣubu
ninu aiṣedẽde wọn, Juda yio si ṣubu pẹlu
wọn.
6 Nwọn o lọ ti awọn ti agbo-ẹran wọn
ati ọ̀wọ-ẹran wọn lati wá Oluwa: ṣugbọn
nwọn ki o ri i, on ti fà ara rẹ̀ sẹhin kuro
lọdọ wọn.
7 Nwọn ti hùwa arekerekè si Oluwa:
nitori nwọn ti bi ajẹ̀ji ọmọ: nisisiyi li oṣù
titun yio jẹ wọn run, pẹlu ipin wọn.
8 Ẹ fun korneti ni Gibea, ati ipè ni
Rama; kigbe kikan ni Bet-afeni, lẹhin rẹ,
iwọ Benjamini.
9 Efraimu yio di ahoro li ọjọ ibawi:
ninu awọn ẹyà Israeli li emi ti fi ohun ti o
wà nitõtọ hàn.
10 Awọn olori Juda dàbi awọn ti o yẹ̀
oju àla: lara wọn li emi o tú ibinu mi si bi
omi.
11 A tẹ̀ ori Efraimu ba, a si ṣẹgun rẹ̀
ninu idajọ, nitoriti on mọ̃mọ̀ tẹ̀le ofin na.
12 Nitorina ni emi o ṣe dabi kòkoro aṣọ
si Efraimu, ati si ile Juda bi idin.
13 Nigbati Efraimu ri arùn rẹ̀, ti Juda
si ri ọgbẹ́ rẹ̀, nigbana ni Efraimu tọ̀ ara
Assiria lọ, o si ranṣẹ si ọba Jarebu; ṣugbọn
on kò le mu ọ lara da, bẹ̃ni kò le wò ọgbẹ
rẹ jiná.
14 Nitori emi o dàbi kiniun si Efraimu,
ati bi ọmọ kiniun si ile Juda, emi, ani emi
o fàya, emi o si lọ, emi o mu lọ, ẹnikẹni ki
o si gbà a silẹ.
15 Emi o padà lọ si ipò mi, titi nwọn o
fi jẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn, ti nwọn o si wá oju mi:
ninu ipọnju wọn, nwọn o wá mi ni kùtu-
kùtu.

Digitized by Google

## ORI 6.

E WÁ, ę ję ki a yipadà si Oluwa: nitori
o ti fà wa ya, on o si mu wa lara da;
o ti lù wa, yio si tun wa dì.
2 Lẹhìn ijọ meji, yio tún wa jí: ni ijọ
kęta yio ji wa dide, awa o si wà lãyè niwaju
rẹ̀.
3 Nigbana li awa o mọ̀, bi a ba tęramọ́
ati mọ̀ Oluwa: ati pèse ijadelọ rẹ̀ bi owùrọ:
on o si tọ̀ wa wá bi ojò: bi arọ̀kuro ati
akọrọ̀ òjo si ilę.
4 Efraimu, kili emi o şe si ọ? Juda,
kili emi o şe si ọ? nitori ore nyin dàbi
ikuku owurọ̀, ati bi ìri kùtukùtu ti o kọja
lọ.
5 Nitorina ni mo şe fi ãké ké wọn lati
ọwọ awọn woli; mo ti fi ọ̀rọ ẹnu mi pa wọn:
ki idajọ rẹ le ri bi imọlẹ ti o jade lọ.
6 Nitori ãnu ni mo fẹ́, ki işe ẹbọ; ati
ìmọ Ọlọrun jù ọrẹ-ẹbọ sisun lọ.
7 Şugbọn bi Adamu nwọn ti dá majemu
kọja: nibẹ̀ ni nwọn ti şẹ̀tan si mi.
8 Gileadi ni ilu awọn ti nşişẹ ẹ̀şẹ, a si ti
fi ẹ̀jẹ bà a jẹ.
9 Ati gẹgẹ bi ọwọ́ ole ti lùmọ dè enia,
bẽni ẹgbẹ́ awọn alufa fohùnşọ̀kan lati pania
li ọ̀na: nitori nwọn dá ẹ̀şẹ nla.
10 Mo ti ri ohun buburu kan ni ile
Israeli: agbère Efraimu wà nibẹ̀, Israeli ti
bajẹ.
11 Iwọ Juda pẹlu, on ti gbe ikorè kalẹ
fun ọ, nigbati mo ba yi igbèkun awọn enia
mi padà.

## ORI 7.

NIGBATI emi iba mu Israeli li ara dá,
nigbana ni ẹ̀şẹ Efraimu fi ara hàn, ati
ìwa-buburu Samaria; nitori nwọn şeké:
olè si wọle, ọwọ́ olè si nkoni lode.
2 Nwọn kò si rò li ọkàn wọn pe, emi
ranti gbogbo ìwa-buburu wọn: nisisiyi işẹ
ara wọn duro yi wọn ka; nwọn wà niwaju
mi.
3 Nwọn fi ìwa-buburu wọn mu ki ọba
yọ̀; nwọn si fi eké wọn mu awọn ọmọ-alade
yọ̀.
4 Gbogbo nwọn ni panşagà, bi ãrò ti ala-
kàra mu gboná, ti o dawọ́ kikoná duro,
lẹhìn igbati o ti pò iyẹ̀fun tan, titi yio fi
wú.
5 Li ọjọ ọba wa, awọn ọmọ-alade ti fi
oru ọti-waini mu u şaisàn; o nà ọwọ́ rẹ̀
jade pẹlu awọn ẹlẹgàn.
6 Nitori nwọn ti mura ọkàn wọn silẹ bi
ãrò, nigbati nwọn ba ni buba: alakàra wọn
sùn ni gbogbo oru; li owurọ̀ o jo bi ọwọ́-
iná.
7 Gbogbo wọn gboná bi ãrò, nwọn ti jẹ
awọn onidajọ wọn run; gbogbo ọba wọn
şubu: kò si ẹnikan ninu wọn ti o ke pè
mi.
8 Efraimu, on ti dà ara rẹ̀ pọ̀ mọ awọn
enia na; Efraimu ni akàra ti a kò yipadà.
9 Awọn alejò ti jẹ agbara rẹ̀ run, on kò
si mọ̀: nitõtọ, ewú wà kakiri li ara rẹ̀,
sibẹ̀ on kò mọ̀.
10 Igberaga Israeli si njẹri si i li oju
rẹ̀; nwọn kò si yipadà si Oluwa Ọlọrun
wọn, bẽni fun gbogbo eyi nwọn kò si wá a.
11 Efraimu pẹlu dabi òpe adàba ti kò li
ọkàn; nwọn kọ si Egipti, nwọn lọ si
Assiria.
12 Nigbati nwọn o lọ, emi o nà àwọn
mi le wọn; emi o mu wọn wá ilẹ bi ẹiyẹ
oju-ọrun; emi o nà wọn, bi ijọ-enia wọn
ti gbọ́.
13 Egbe ni fun wọn! nitori nwọn ti sá
kuro lọdọ mi: iparun ni fun wọn! nitori
nwọn ti şẹ̀ si mi: bi o tilẹ şepe mo ti rà
wọn padà, şugbọn nwọn ti şe eké si mi.
14 Nwọn kò si ti fi tọkàntọkàn ké pè
mi, nigbati nwọn hu lori akete wọn: nwọn
kó ara wọn jọ fun ọkà ati ọti-waini, nwọn
si şọ̀tẹ si mi.
15 Bi mo ti dì, ti mo si fun apa wọn li
okun, sibẹ̀ nwọn nrò ibi si mi.
16 Nwọn yipadà, şugbọn kì işe si Ọga-
ogo: nwọn dàbi ọrun ẹtàn; awọn ọmọ-
alade wọn yio tipa idà şubu, nitori irúnu
ahọn wọn: eyi ni yio şe ẹsín wọn ni ilẹ
Egipti.

## ORI 8.

FI ipè si ẹnu rẹ. Yio wá bi idì si ile Olu-
wa, nitori nwọn ti re majẹmu mi kọja,
nwọn si ti rú ofin mi.
2 Nwọn o kigbe si mi pe, Ọlọrun mi, awa
Israeli mọ̀ ọ.
3 Israeli ti gbe ohunrere sọnù; ọta yio
lepa rẹ̀.
4 Nwọn ti fi ọba jẹ, şugbọn kì işe
nipasẹ̀ mi: nwọn ti jẹ olori, şugbọn emi
kò si mọ̀: fàdakà wọn ati wurà wọn ni
nwọn fi şe òrişa fun ara wọn, ki a ba le ké
wọn kuro.
5 Ọmọ-malu rẹ ti ta ọ nù, Samaria;
ibinu mi rú si wọn: yio ti pẹ to ki nwọn
to de ipò ailẹ̀şẹ?
6 Nitori lati ọdọ Israeli wá li o ti ri bẽ
pẹlu; onişọ̀na li o şe e; nitorina on kì işe

Digitized by Google

Ọlọrun: ṣugbọn ọmọ malu Samaria yio fọ tũtũ.

7 Nitori nwọn ti gbìn ẹfũfũ, nwọn o si ka ãjà: kò ni igi ọka: irúdi kì yio si mu onjẹ wá: bi o ba ṣepe o mu wá, alejò yio gbe e mì.

8 A gbe Israeli mì: nisisiyi ni nwọn o wà lãrin awọn Keferi bi ohun-elò ninu eyiti inu-didùn kò si.

9 Nitori nwọn goke lọ si Assiria, kẹtẹ́kẹtẹ́ igbẹ́ nikan fun ara rẹ̀: Efraimu ti bẹ̀ awọn ọrẹ li ọ̀wẹ.

10 Nitõtọ, bi nwọn tilẹ ti bẹ̀ ọ̀wẹ lãrin awọn orilẹ-ède, nisisiyi li emi o ko wọn jọ, nwọn o si kãnu diẹ fun ẹrù ọba awọn ọmọ-alade.

11 Nitori Efraimu ti tẹ́ pẹpẹ pupọ̀ lati dẹṣẹ, pẹpẹ yio jẹ ohun atidẹṣẹ fun u.

12 Mo ti kọwe ohun pupọ̀ ti ofin mi si i, ṣugbọn a kà wọn si bi ohun ajèji.

13 Nwọn rubọ ẹran ninu ẹbọ ẹran mi, nwọn si jẹ ẹ; Oluwa kò tẹwọgbà wọn; nisisiyi ni yio ránti ìwa-buburu wọn, yio si bẹ̀ ẹ̀ṣẹ wọn wò: nwọn o padà lọ si Egipti.

14 Nitori Israeli ti gbagbe Ẹlẹda rẹ̀, o si kọ́ tempili pipọ; Juda si ti sọ ilu olodi di pupọ̀: ṣugbọn emi o rán iná kan si ori awọn ilu rẹ̀, yio si jẹ awọn ãfin rẹ̀ wọnni run.

## ORI 9.

MÁṢE yọ̀, Israeli, fun ayọ̀, bi awọn enia miran: nitori iwọ ti ṣe agbère lọ kuro lọdọ Ọlọrun rẹ, iwọ ti fẹ́ èrè lori ilẹ ipakà gbogbo.

2 Ilẹ ipakà ati ohun ifunti kì yio bọ́ wọn, ọti-waini titun yio si tan ninu rẹ̀.

3 Nwọn kì yio gbe inu ilẹ Oluwa; ṣugbọn Efraimu yio padà si Egipti, nwọn o si jẹ ohun aimọ́ ni Assiria.

4 Nwọn kì yio ta Oluwa li ọrẹ ọti-waini, bẽni nwọn kì yio mu u ni inu dùn: ẹbọ wọn yio ri fun wọn bi onjẹ awọn ti nṣọ̀fọ; gbogbo awọn ti o jẹ ninu rẹ̀ ni yio di alaimọ́: nitori onjẹ wọn kì yio wá si ile Oluwa fun ọkàn wọn.

5 Kili ẹnyin o ṣe li ọjọ ti o ni irònu, ati li ọjọ àse Oluwa?

6 Nitori, sa wò o, nwọn ti lọ nitori ikogun: Egipti yio kó wọn jọ, Memfisi yio sin wọn: ibi didara fun fadakà wọn li ẹgún-ọ̀gan yio jogun wọn: ẹgún yio wà ninu agọ wọn.

7 Ọjọ ibẹ̀wo de, ọjọ ẹsan de; Israeli yio mọ̀: asiwère ni woli na, ẹni ẹmi na nsinwin; nitori ọ̀pọlọpọ ẹ̀ṣẹ rẹ, ati irira nla na.

8 Olùṣọ Efraimu wà pẹlu Ọlọrun mi: ṣugbọn okùn pẹyẹpẹyẹ ni woli na li ọ̀na rẹ̀ gbogbo, ati irira si ile Ọlọrun rẹ̀.

9 Nwọn ti ba ara wọn jẹ pipọ̀pipọ̀, bi li ọjọ Gibea: nitorina, on o ranti aiṣedẽde wọn, yio bẹ̀ ẹ̀ṣẹ wọn wò.

10 Mo ri Israeli bi eso ajara li aginjù; mo ri awọn baba nyin bi akọpọ́n ninu igi ọpọ̀tọ li akọso rẹ̀: ṣugbọn nwọn tọ̀ Baal-peori lọ, nwọn si yà ara wọn si itiju nì; ohun irira wọn si ri gẹgẹ bi nwọn ti fẹ.

11 Bi o ṣe ti Efraimu, ogo wọn yio fò lọ bi ẹiyẹ, lati ibí, ati lati inu, ati lati iloyun.

12 Bi nwọn tilẹ tọ́ ọmọ wọn dàgba, ṣugbọn emi o gbà wọn li ọwọ wọn, ti kì yio fi kù enia kan; lõtọ, egbe ni fun wọn pẹlu nigbati mo ba kuro lọdọ wọn!

13 Efraimu, bi mo ti ri Tirusi, li a gbìn si ibi daradara: ṣugbọn Efraimu yio bi ọmọ rẹ̀ fun apania.

14 Fun wọn, Oluwa, li ohun ti iwọ o fun wọn? fun wọn ni iṣẹnu ati ọmú gbigbẹ́.

15 Gbogbo ìwa-buburu wọn mbẹ ni Gilgali; nitori nibẹ̀ ni mo korira wọn; nitori ìwa-buburu iṣe wọn, emi o le wọn kuro ni ile mi, emi kì yio fẹràn wọn mọ́; gbogbo ọmọ-alade wọn ni ọlọ̀tẹ.

16 A lù Efraimu, gbòngbo wọn gbẹ, nwọn kì yio so eso, bi nwọn tilẹ bi ọmọ, ṣugbọn emi o pa ãyò eso inu wọn.

17 Ọlọrun mi yio sọ wọn nù, nitoriti nwọn kò fetisi tirẹ̀; nwọn o si di alarinkiri lãrin awọn keferi.

## ORI 10.

AJARA ofo ni Israeli, o nso eso fun ara rẹ̀; gẹgẹ bi ọ̀pọ eso rẹ̀ li o mu pẹpẹ pọ̀ si i; gẹgẹ bi didara ilẹ rẹ̀ ni nwọn yà ere daradara.

2 Ọkàn wọn dá meji; nisisiyi ni nwọn o jẹbi; on o wó pẹpẹ wọn lulẹ, on o si ba ere wọn je.

3 Nitori nisisiyi ni nwọn o wipe, Awa kò li ọba, nitoriti awa kò bẹ̀ru Oluwa; njẹ kili ọba o ṣe fun wa?

4 Nwọn ti sọ ọ̀rọ, nwọn mbura eke ni didà majẹmu: bayi ni idajọ hù soke bi igi iwọ, ni aporo oko.

5 Nitori awọn ọmọ-malu Bet-afeni, awọn ti ngbe Samaria yio bẹ̀ru: nitori awọn enia ibẹ̀ yio ṣọ̀fọ lori rẹ̀, ati awọn baba-oloriṣà ibẹ̀ ti o yọ̀ lori rẹ̀, nitori ogo rẹ̀, nitori o ti lọ kuro lọdọ rẹ̀.

6 A o si mu u lọ si Assiria pẹlu ẹbùn

Digitized by Google

fun Jarebu ọba: Efraimu yio gbà itiju,
oju yio si tì Israeli nitori igbimọ rẹ̀.
7 Bi o ṣe ti Samaria, a ke ọba rẹ̀ kuro bi
ifofo loju omi.
8 Ibi giga Afeni pẹlu, ẹ̀ṣẹ Israeli, li a o
parun; ẹgún ọ̀gan on oṣuṣu yio hù jade
lori pẹpẹ wọn; nwọn o si wi fun awọn oke-
nlą pe, Bò wa mọlẹ; ati fun awọn oke
kékèké pe, Wó lù wa.
9 Lati ọjọ Gibea ni iwọ ti ṣẹ̀, Israeli:
nibẹ̀ ni nwọn duro: ogun Gibea si awọn
ọmọ ẹ̀ṣẹ kò le wọn ba.
10 Ifẹ inu mi ni ki nle nà wọn; a o si
gbá awọn enia jọ si wọn, lati di ara wọn si
ẹ̀ṣẹ wọn mejeji.
11 Efraimu si dabi ọmọ-malu ti a kọ́, ti
o si fẹ́ lati ma tẹ ọkà; ṣugbọn emi rekọja
li ori ọrùn rẹ̀ ti o ni ẹwà: emi o mu ki
Efraimu gùn ẹṣin; Juda yio tú ilẹ, Jakobu
yio si fọ́ ogulùtu rẹ̀.
12 Ẹ furùngbin fun ara nyin li ododo, ẹ
ká li ãnu: ẹ tú ilẹ nyin ti a kò ro: nitori
o to akokò lati wá Oluwa, titi yio fi de, ti
yio si fi rọ̀jo ododo si nyin.
13 Ẹnyin ti tulẹ ìwa-buburu, ẹnyin ti
ká aiṣedẽde; ẹnyin ti jẹ eso eke: nitori
iwọ gbẹkẹ̀le ọ̀na rẹ, ninu ọ̀pọlọpọ awọn
alagbara rẹ.
14 Nitorina li ariwo yio dide ninu awọn
enia rẹ, gbogbo awọn odi agbara rẹ li a o si
bajẹ, bi Ṣalmani ti ba Bet-abeli jẹ li ọjọ
ogun: a fọ́ iya tũtũ lori awọn ọmọ rẹ̀.
15 Bẽni Beteli yio ṣe si nyin, nitori ìwa-
buburu nla nyin; ni kùtukùtu li a o ke
ọba Israeli kuro patapata.

## ORI 11.

NIGBATI Israeli wà li ọmọde, nigbana
ni mo fẹ́ ẹ, mo si pè ọmọ mi lati
Egipti jade wá.
2 Bi nwọn ti pè wọn, bẽni nwọn lọ kuro
lọdọ wọn: nwọn rubọ si Baalimu, nwọn si
fi turari joná si ere fifin.
3 Mo kọ́ Efraimu pẹlu lati rìn, mo dì
wọn mu li apa, ṣugbọn nwọn kò mọ̀ pe mo
ti mu wọn lara dá.
4 Mo fi okùn enia fà wọn, ati idè ifẹ:
mo si ri si wọn bi awọn ti o mu ajàga kuro
li ẹrẹkẹ wọn, mo si gbe onjẹ kalẹ niwaju
wọn.
5 On kì yio yipadà si ilẹ Egipti, ṣugbọn
ara Assiria ni yio jẹ ọba rẹ̀, nitori nwọn kọ̀
lati yipadà.
6 Idà yio si ma gbe inu ilu rẹ̀, yio si
run ìtikun rẹ̀, yio si jẹ wọn run, nitori
ìmọran ara wọn.
7 Awọn enia mi si tẹ̀ si ifàsẹhin kuro
lọdọ mi: bi o tilẹ̀ ṣepe nwọn pè wọn si
Ọga-ogo jùlọ, nwọn kò jumọ gbe e ga.
8 Emi o ha ṣe jọwọ rẹ lọwọ, Efraimu?
emi o ha ṣe gbà ọ silẹ, Israeli? emi o ha ti
ṣe ṣe ọ bi Adma? emi o ha ti ṣe gbe ọ kalẹ
bi Seboimu, ọkàn mi yi ninu mi, iyọnu
mi gbiná pọ̀.
9 Emi kì yio mu gbigboná ibinu mi ṣẹ,
emi kì yio yipadà lati run Efraimu: nitori
Ọlọrun li emi, kì iṣe enia; Ẹni-Mimọ lãrin
rẹ: emi kì yio si wá ninu ibinu.
10 Nwọn o ma tẹ̀le Oluwa: on o ke
ramùramù bi kiniun: nigbati on o ke,
nigbana li awọn ọmọ yio wariri lati yama
wá.
11 Nwọn o warìri bi ẹiyẹ lati Egipti wá,
ati bi adàba lati ilẹ Assiria wá: emi o si fi
wọn si ile wọn, li Oluwa wi.
12 Efraimu fi eke sagbàra yi mi ka, ilẹ
Israeli si fi ẹtàn sagbàra yi mi ka: ṣugbọn
Juda njọba sibẹ̀ pẹlu Ọlọrun, o si ṣe olõtọ
pẹlu Ẹni-mimọ́.

## ORI 12.

EFRAIMU njẹ afẹ̃fẹ, o si ntọ̀ afẹ̃fẹ̀ gabasi
lẹhìn: o nmu eke ati iparun pọ̀ si i
lojojumọ; nwọn si ba awọn ara Assiria da
majẹmu, nwọn si nrù ororo lọ si Egipti.
2 Oluwa ni ẹjọ kan ba Juda rò pẹlu, yio
si jẹ Jakobu ni iyà gẹgẹ bi ọ̀na rẹ̀; gẹgẹ bi
iṣe rẹ̀ ni yio san padà fun u.
3 O di arakọnrin rẹ̀ mu ni gigisẹ̀ ni inu,
ati nipa ipá rẹ̀ o ni agbara pẹlu Ọlọrun.
4 Nitõtọ, o ni agbara lori angeli, o si
bori: o sọkun, o si bẹ̀bẹ lọdọ rẹ̀: o ri i ni
Beteli, nibẹ̀ li o gbe ba wa sọ̀rọ;
5 Ani Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun;
Oluwa ni iranti rẹ̀.
6 Nitorina, iwọ yipadà si Ọlọrun rẹ: pa
ãnu ati idajọ mọ, ki o si ma duro de Ọlọrun
rẹ nigbagbogbo.
7 Kenaani ni, iwọ̀n ẹtàn mbẹ li ọwọ́ rẹ̀:
o fẹ lati ninilara.
8 Efraimu si wipe, Ṣugbọn emi di ọlọrọ̀,
mo ti ri ini fun ara mi: ninu gbogbo lãlã
mi nwọn kì yio ri aiṣedẽde kan ti iṣe ẹ̀ṣẹ
lara mi.
9 Ati emi, Oluwa Ọlọrun rẹ lati ilẹ̀
Egipti wá, yio si tún mu ọ gbe inu agọ, bi
ọjọ ajọ-ọ̀wọ wọnni.
10 Emi ti sọ̀rọ nipa awọn woli pẹlu, mo
si ti mu iran di pipọ̀, mo ti ṣe ọ̀pọlọpọ
akàwe, nipa ọwọ́ awọn woli.
11 Aiṣedẽde mbẹ ni Gileadi bi? nitõtọ
asan ni nwọn: nwọn rubọ akọ malu ni

Digitized by Google

Gilgali ; nitõtọ, pẹpẹ wọn dabi ebè ni aporo
oko.
12 Jakobu si salọ si ilẹ Siria : Israeli si
sin nitori aya kan ; ati nitori aya kan li o
ṣọ agùtan.
13 Ati nipa woli kan ni Oluwa mu Israeli
jade ni Egipti : nipa woli kan li a si pa
on mọ.
14 Efraimu mu u binu kikorò : nitorina
ni yio fi ẹjẹ̀ rẹ̀ si ori rẹ̀, ẹgàn rẹ̀ li Oluwa rẹ̀
yio si san padà fun u.

## ORI 13.

NIGBATI Efraimu sọ̀rọ, ìwarìri ni ; o gbe
ara rẹ̀ ga ni Israeli ; ṣugbọn nigbati o
ṣẹ̀ ninu Baali, o kú.
2 Nisisiyi, nwọn si dá ẹ̀ṣẹ kún ẹ̀ṣẹ, nwọn
si ti fi fàdakà wọn ṣe ere didà fun ara wọn,
ati òriṣa ìmọ wọn : iṣẹ oniṣọnà ni gbogbo
rẹ̀ ; nwọn wi niti wọn pe, Jẹ ki awọn enia
ti nrubọ fi ẹnu kò awọn ọmọ malu li ẹnu.
3 Nitorina ni nwọn o ṣe dabi kũkũ
owurọ̀, ati bi ìrì owurọ̀ ti nkọja lọ, bi iyangbò
ti a ti ọwọ́ ìjì gbá kuro ninu ilẹ ipakà,
ati bi ẽfin ti ijade kuro ninu ile ẽfin.
4 Ṣugbọn emi li Oluwa Ọlọrun rẹ lati ilẹ
Egipti wá, iwọ kì yio si mọ̀ ọlọrun kan
bikòṣe emi : nitori kò si olugbàla kan lẹhìn
mi.
5 Emi ti mọ̀ ọ li aginjù, ni ilẹ ti o
pọngbẹ.
6 Gẹgẹ bi a ti bọ́ wọn, bẹ̃ni nwọn yó ;
nwọn yó, nwọn si gbe ọkàn wọn ga ; nitorina
ni nwọn ṣe gbagbe mi.
7 Nitorina li emi o ṣe dabi kiniun si
wọn ; emi o si ma ṣọ wọn bi ẹkùn li ẹ̀ba
ọ̀na.
8 Emi o pade wọn bi beari ti a gbà li
ọmọ, emi o si fà àwọn ọkàn wọn ya, nibẹ̀ li
emi o si jẹ wọn run bi kiniun, ẹranko igbẹ
ni yio fà wọn ya.
9 Israeli, iwọ ti pa ara rẹ run, niti pe
iwọ wà lodi si emi, irànlọwọ rẹ.
10 Nibo li ọba rẹ gbe wà nisisiyi ninu
gbogbo ilu rẹ, ti o le gbà ọ ? ati awọn onidajọ
rẹ, niti awọn ti iwọ wipe ; Fun mi li
ọba ati awọn ọmọ-alade.
11 Emi fun ọ li ọba ni ibinu mi, mo si
mu u kuro ni irúnu mi.
12 A dì aiṣedẽde Efraimu ; ẹ̀ṣẹ rẹ̀ pamọ.
13 Irora obirin ti nrọbi yio de si i : alaigbọn
ọmọ li on ; nitori on kò duro li akokò
si ibi ijade ọmọ.
14 Emi o rà wọn padà lọwọ agbara isàokú ;
Emi o rà wọn padà lọwọ ikú ; Ikú,
ajàkalẹ arùn rẹ dà ? Isà-okú, iparun rẹ
dà ? ironupiwàda yio pamọ kuro loju mi.
15 Bi on tilẹ ṣe eleso ninu awọn arakọnrin
rẹ̀, afẹ̃fẹ́ ilà-õrùn kan yio de, afẹ̃fẹ́
Oluwa yio ti aginjù wá, orìsun rẹ̀ yio si
gbẹ, ati oju isun rẹ̀ li a o mu gbẹ : on o bà
ohun elò daradara gbogbo jẹ.
16 Samaria yio di ahoro : nitoriti on ti
ṣọ̀tẹ si Ọlọrun rẹ̀ : nwọn o ti ipa idà ṣubu :
a o fọ́ ọmọ wọn tũtũ, ati aboyún wọn li a o
là ni inu.

## ORI 14.

ISRAELI, yipadà si Oluwa Ọlọrun rẹ,
nitori iwọ ti ṣubu ninu aiṣedẽde rẹ.
2 Mu ọ̀rọ pẹlu nyin, ẹ si yipadà si Oluwa :
ẹ wi fun u pe, Mu aiṣedẽde gbogbo
kuro, si fi ore-ọfẹ gbà wa : bẹ̃ni awa o fi
ọmọ malu ète wa san a fun ọ.
3 Assuru kì yio gbà wa ; awa kì yio gùn
ẹṣin : bẹ̃ni awa kì yio tun wi mọ fun iṣẹ
ọwọ́ wa pe, Ẹnyin li ọlọrun wa : nitori lọdọ
rẹ ni alainibaba gbe ri ãnu.
4 Emi o wo ifàsẹhìn wọn sàn, emi o fẹ
wọn lọfẹ : nitori ibinu mi yí kuro lọdọ rẹ̀.
5 Emi o dabi ìri si Israeli : on o tanná
bi eweko lili ; yio si ta gbòngbo rẹ̀ bi
Lebanoni.
6 Ẹka rẹ̀ yio tàn, ẹwà rẹ̀ yio si dabi igi
olifi, ati õrùn rẹ̀ bi Lebanoni.
7 Awọn ti o ngbe abẹ ojiji rẹ̀ yio padà
wá ; nwọn o sọji bi ọkà : nwọn o si tanná
bi àjara : õrun rẹ̀ yio dabi ọti-waini ti
Lebanoni.
8 Efraimu yio wipe, Kili emi ni fi òriṣa
ṣe mọ ? Emi ti gbọ́, mo si ti kiyesi i : emi
dabi igi firi tutù. Lati ọdọ mi li a ti ri èso
rẹ.
9 Tali o gbọ́n, ti o lè moye nkan wọnyi !
tali o li oye, ti o le mọ̀ wọn ? nitori ọ̀na
Oluwa tọ́, awọn olododo yio si ma rìn ninu
wọn : ṣugbọn awọn alarekọja ni yio ṣubu
sinu wọn.

Digitized by Google

# JOELI.

## ORI 1.

ỌRỌ Oluwa ti o tọ̀ Joeli ọmọ Petueli
wá.
2 Gbọ́ eyi, ẹnyin arugbo, si fi eti silẹ,
gbogbo ẹnyin ará ilẹ na. Eyi ha wà li ọjọ
nyin, tabi li ọjọ awọn baba nyin?
3 Ẹ sọ ọ fun awọn ọmọ nyin, ati awọn
ọmọ nyin fun awọn ọmọ wọn, ati awọn ọmọ
wọn fun iran miràn.
4 Eyi ti iru kòkoro kan jẹ kù ni ẽṣú jẹ;
ati eyi ti ẽṣú jẹ kù ni kòkoro miràn jẹ;
eyiti kòkoro na si jẹ kù ni kòkoro miràn
jẹ.
5 Ji, ẹnyin ọmùti, ẹ si sọkun; si hu,
gbogbo ẹnyin ọmùti waini, nitori ọti-waini
titun; nitoriti a ké e kuro li ẹnu nyin.
6 Nitori orilẹ-ède kan goke wá si ilẹ mi,
o li agbara, kò si ni iye, ehin ẹniti iṣe ehin
kiniun, o si ni erìgi abo kiniun.
7 O ti pa àjara mi run, o si ti ya ẹ̀ka igi
ọ̀pọtọ́ mi kuro, o ti bó o jalẹ, o si sọ ọ nù;
awọn ẹ̀ka rẹ̀ li a si sọ di funfun.
8 Ẹ pohùnrére-ẹkun bi wundia ti a fi aṣọ
ọ̀fọ dì li àmure, nitori ọkọ igbà ewe rẹ̀.
9 A ké ọrẹ-jijẹ ati ọrẹ-mimu kuro ni ile
Oluwa; awọn alufa, awọn iranṣẹ Oluwa,
ṣọ̀fọ.
10 Oko di ìgboro, ilẹ nṣọ̀fọ, nitori a fi
ọkà ṣòfo: ọti-waini titun gbẹ, ororo mbuṣe.
11 Ki oju ki o tì nyin, ẹnyin agbẹ̀; ẹ
hu, ẹnyin olùtọju àjara, nitori alikamà ati
nitori ọkà barli; nitori ikorè oko ṣègbe.
12 Ajara gbẹ, igi ọ̀pọtọ́ si rọgbẹ; igi
pomegranate, igi ọ̀pẹ pẹlu, ati igi appili,
gbogbo igi igbo li o rọ: nitoriti ayọ̀ rọgbẹ
kuro lọdọ awọn ọmọ enia.
13 Ẹ dì ara nyin li amùre, si pohùnrére
ẹkún ẹnyin alufa: ẹ hu, ẹnyin iranṣẹ pẹpẹ:
ẹ wá, fi gbogbo oru dùbulẹ ninu aṣọ-ọ̀fọ,
ẹnyin iranṣẹ Ọlọrun mi: nitori ti a dá ọrẹ-
jijẹ, ati ọrẹ-mimu duro ni ile Ọlọrun nyin.
14 Ẹ yà àwẹ kan si mimọ́, ẹ pè ajọ kan
ti o ni irònu, ẹ pè awọn agbà, ati gbogbo
awọn ará ilẹ na jọ si ile Oluwa Ọlọrun nyin,
ki ẹ si kepe Oluwa,
15 A! fun ọjọ na, nitori ọjọ Oluwa
kù si dẹ̀dẹ, ati bi iparun lati ọwọ́ Olodu-
mare ni yio de.
16 A kò ha ké onjẹ kuro niwaju oju wa,
ayọ̀ ati inu didùn kuro ninu ile Ọlọrun
wa?
17 Irugbìn bajẹ ninu ebè wọn, a sọ aká
di ahoro, a wó abà palẹ; nitoriti a mu ọ̀ka
rọ.
18 Awọn ẹranko ti nkerora to! awọn
agbo-ẹran dãmu, nitoriti nwọn kò ni papa
oko; nitõtọ, a sọ awọn agbo agùtan di
ahoro.
19 Oluwa, si ọ li emi o ké, nitori iná ti
run pápa oko tutú aginju, ọwọ́ iná si ti jo
gbogbo igi igbẹ.
20 Awọn ẹranko igbẹ gbé oju soke si ọ
pẹlu: nitoriti awọn iṣàn omi gbẹ, iná si ti
jó awọn pápa oko aginju run.

## ORI 2.

Ẹ FUN ipè ni Sioni, ẹ si dá idagìri ni oke
mimọ́ mi; jẹ ki awọn ará ilẹ na wa-
rìri: nitoriti ọjọ Oluwa mbọ̀ wá, nitori o
kù si dẹ̀dẹ;
2 Ọjọ òkunkun ati òkudu, ọjọ ikũku ati
òkunkun biribiri, bi ọyẹ̀ owurọ̀ ti ilà bò ori
awọn oke-nla: enia nla ati alagbara; kò
ti isi iru rẹ̀ ri, bẹ̃ni iru rẹ̀ kì yio si mọ lẹhin
rẹ̀, titi de ọdun iran de iran.
3 Iná njó niwaju wọn; ọwọ́-iná si njó
lẹhin wọn: ilẹ na dàbi ọgbà Edeni niwaju
wọn, ati lẹhin wọn bi ahoro ijù; nitõtọ, kò
si si ohun ti yio bọ́ lọwọ wọn.
4 Irí wọn dàbi irí awọn ẹṣin; ati bi
awọn ẹlẹṣin, bẹ̃ni nwọn o sure.
5 Bi ariwo kẹkẹ́ lori oke ni nwọn o fò,
bi ariwo ọwọ́-iná ti o jó koriko gbigbẹ, bi
alagbara enia ti a tẹ́ ni itẹ́gun.
6 Li oju wọn, awọn enia yio jẹ irora
pupọ̀: gbogbo oju ni yio ṣú dúdu.
7 Nwọn o sare bi awọn alagbara; nwọn
o gùn odi bi ọkọnrin ologun; olukuluku
wọn o si rìn lọ li ọ̀na rẹ̀, nwọn kì yio si bà
ọ̀wọ́ wọn jẹ.
8 Bẹ̃ni ẹnikan kì yio tì ẹnikeji rẹ̀; olu-
kuluku wọn o rìn li ọ̀na rẹ̀: nigbati nwọn
ba si ṣubu lù idà, nwọn kì o gbọgbẹ́.
9 Nwọn o sure siwa sẹhin ni ilu: nwọn

Digitized by Google

o sure lori odi, nwọn o gùn ori ile; nwọn
o gbà oju fèrese wọ̀ inu ile bi olè.
10 Aiye yio mì niwaju wọn; awọn ọrun
yio warìri: õrùn ati oṣupa yio ṣu òkunkun,
awọn iràwọ yio si fà imọlẹ wọn sẹhìn.
11 Oluwa yio si fọ̀ ohùn rẹ̀ jade niwaju
ogun rẹ̀: nitori ibùdo rẹ̀ tobi gidigidi: ni-
tori alagbara li on ti nmu ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ; nitori
ọjọ Oluwa tobi.o si li ẹ̀ru gidigidi; ara tali
o le gbà a?
12 Njẹ nitorina nisisiyi, ni Oluwa wi, Ẹ
fi gbogbo ọkàn nyin yipada si mi, ati pẹlu
ãwẹ̀, ati pẹlu ẹkún, ati pẹlu ọ̀fọ.
13 Ẹ si fà aiyà nyin ya, kì isi ṣe aṣọ
nyin, ẹ si yipadà si Oluwa Ọlọrun nyin,
nitoriti o pọ̀ li ore-ọfẹ, o si kún fun ãnu, o
lọra lati binu, o si ṣeun pupọ̀, o si ronupi-
wada ati ṣe buburu.
14 Tali o mọ̀ bi on o yipadà, ki o si ronu-
piwàda, ki o si fi ibukún silẹ̀ lẹhin rẹ̀;
ani ọrẹ-jijẹ atĩ ọrẹ-mimu fun Oluwa Ọlọrun
nyin?
15 Ẹ fun ipè ni Sioni, ẹ yà ãwẹ̀ kan si
mimọ́, ẹ pè ajọ ti o ni irònu.
16 Ẹ kó awọn enia jọ, ẹ yà ijọ si mimọ́,
ẹ pè awọn àgba jọ, ẹ kó awọn ọmọde jọ,
ati awọn ti nmu ọmú: jẹ ki ọkọ iyàwo
jade kuro ni iyẹ̀wu rẹ̀, ati iyàwo kuro ninu
iyẹ̀wu rẹ̀.
17 Jẹ ki awọn alufa, awọn iranṣẹ Oluwa,
sọkún lãrin iloro ati pẹpẹ, si jẹ ki wọn wi
pe, Dá awọn enia rẹ si, Oluwa, má si ṣe fi
iní rẹ fun ẹ̀gan, ti awọn keferi yio fi ma
jọba lori wọn: ẽṣe ti nwọn o fi wi ninu
awọn enia pe, Ọlọrun wọn há da?
18 Nigbana ni Oluwa yio jowú fun ilẹ
rẹ̀, yio si kãnu fun enia rẹ̀.
19 Nitõtọ, Oluwa yio dahùn, yio si wi
fun awọn enia rẹ̀ pe, Wò o emi o rán ọkà,
ati ọti-waini, ati ororo si nyin, a o si fi
wọn tẹ́ nyin lọrùn: emi kì yio si fi nyin
ṣe ẹ̀gan mọ lãrin awọn keferi.
20 Ṣugbọn emi o ṣí ogun ariwa nì jinà
rére kuro lọdọ nyin, emi o si le e lọ si ilẹ
ti o ṣá, ti o si di ahoro, pẹlu oju rẹ̀ si okun
gabasi, ati ẹhìn rẹ̀ si ipẹkùn okun, õrùn rẹ̀
yio si goke, õrùn buburu rẹ̀ yio si goke,
nitoriti o ti ṣe ohun nla.
21 Má bẹ̀ru, iwọ ilẹ; jẹ ki inu rẹ dùn,
ki o si yọ̀: nitori Oluwa yio ṣe ohun nla.
22 Ẹ má bẹ̀ru, ẹranko igbẹ: nitori pápa-
oko aginju nrú, nitori igi nso eso rẹ̀, igi
ọ̀pọtọ ati àjara nso eso ipá wọn.
23 Njẹ jẹ ki inu nyin dùn, ẹnyin ọmọ
Sioni, ẹ si yọ̀ ninu Oluwa Ọlọrun nyin; ni-
toriti o ti fi akọrọ̀ ojò fun nyin bi o ti tọ́,
on o si mu ki ojò rọ̀ silẹ fun nyin, akọrọ̀
ati arọ̀kuro ojò ni oṣù ikini.
24 Ati awọn ilẹ ipakà yio kún fun ọkà,
ati ọpọ́n wọnni yio ṣàn jade pẹlu ọti-waini
ati ororo.
25 Emi o si mu ọdun wọnni padà fun
nyin wá, eyi ti ẽṣú on iru kòkoro jewejewe,
ati iru kòkoro keji, ati iru kòkoro jewejewe
mirãn ti fi jẹ, awọn ogun nla mi ti mo rán
sãrin nyin.
26 Ẹnyin o si jẹun li ọ̀pọlọpọ, ẹ o si yó,
ẹ o si yìn orukọ Oluwa Ọlọrun nyin, ẹniti
o fi iyanu ba nyin lò; oju kì o si tì awọn
enia mi lai.
27 Ẹnyin o si mọ̀ pe, emi wà lãrin Isra-
eli, ati pe: Emi li Oluwa Ọlọrun nyin, kì
iṣe ẹlomirãn: oju kì yio si tì awọn enia mi
lai.
28 Yio si ṣe, nikẹhìn emi o tú ẹmi mi
jade si ara enia gbogbo; ati awọn ọmọ nyin
ọkọnrin, ati awọn ọmọ nyin obirin yio ma
ṣotẹlẹ, awọn arugbo nyin yio ma lá alá,
awọn ọdọmọkọnrin nyin yio ma riran:
29 Ati pẹlu si ara awọn ọmọ-ọdọ ọkọnrin,
ati si ara awọn ọmọ-ọdọ obirin, li emi o tú
ẹmi mi jade li ọjọ wọnni.
30 Emi o si fi iṣẹ iyanu hàn li ọrun ati
li aiye, ẹjẹ̀ ati iná, ati ọwọ̀n ẽfin.
31 A a sọ õrùn di òkunkun, ati oṣùpá di
ẹjẹ̀, ki ọjọ nla ati ẹ̀ru Oluwa to de.
32 Yio si ṣe ẹnikẹni ti o ba ke pè orukọ
Oluwa li a o gbàla: nitori li oke Sioni ati
ni Jerusalemu ni igbàla yio gbe wà, bi
Oluwa ti wi, ati ninu awọn iyokù ti Oluwa
yio pè.

## ORI 3.

NITORINA kiyesi i, li ọjọ wọnni, ati li
akokò na, nigbati emi o tun mu igbè-
kun Juda ati Jerusalemu padà bọ̀.
2 Emi o kó gbogbo orilẹ-ède jọ pẹlu, emi
o si mu wọn wá si afonifojì Jehoṣafati, emi
o si ba wọn wijọ nibẹ̀ nitori awọn enia mi,
ati nitori Israeli iní mi, ti nwọn ti fọ́n
ka sãrin awọn orilẹ̀-ede, nwọn si ti pín ilẹ
mi.
3 Nwọn si ti di ibò fun awọn enia mi;
nwọn si ti fi ọmọdekọnrin kan fun panṣagà
obirin kan, nwọn si ti tà ọmọdebirin kan
fun ọti-waini, ki nwọn ki o le mu.
4 Nitõtọ, ati ki li ẹnyin ni ifi mi ṣe,
ẹnyin Tire ati Sidoni, ati gbogbo ẹkùn
Palestina? ẹnyin o ha san ẹsan fun mi? bi
ẹnyin ba si san ẹsan fun mi, ni kánkan ati
ni koyákoyá li emi o san ẹsan nyin padà
sori ara nyin.

Digitized by Google

5 Nitoriti ẹnyin ti mu fàdakà mi ati
wurà mi, ẹnyin si ti mu ohun rere daradara
mi lọ sinu tempili nyin :
6 Ati awọn ọmọ Juda, ati awọn ọmọ
Jerusalemu li ẹnyin ti tà fun awọn ara
Griki, ki ẹnyin ba le ṣi wọn jina kuro li
agbègbe wọn.
7 Kiyesi i, emi o gbe wọn dide kuro
nibiti ẹnyin ti tà wọn si, emi o si san ẹsan
nyin padà sori ara nyin.
8 Emi o si tà awọn ọmọkọnrin nyin ati
awọn ọmọbirin nyin si ọwọ́ awọn ọmọ
Juda, nwọn o si tà wọn fun awọn ara Sabia,
fun orilẹ-ède kan ti o jinà rére, nitori
Oluwa li o ti sọ ọ.
9 Ẹ kede eyi li ãrin awọn keferi; ẹ yà
ogun si mimọ́, ẹ ji awọn alagbara, ẹ sunmọ
tòsi, ẹ goke wá gbogbo ẹnyin ọkọnrin
ologun.
10 Ẹ fi irin plau nyin rọ idà, ati dojé
nyin rọ ọ̀kọ̀ : jẹ ki alailera wi pe, Ara mi
le koko.
11 Ẹ kó ara nyin jọ, si wá, gbogbo
ẹnyin keferi, ẹ si gbá ara nyin jọ yikakiri :
nibẹ̀ ni ki o mu awọn alagbara rẹ sọkalẹ,
Oluwa.
12 Ẹ ji, ẹ si goke wá si afonifojì Jehoṣa-
fati ẹnyin keferi : nitori nibẹ̀ li emi o joko
lati ṣe idajọ awọn keferi yikakiri.
13 Ẹ tẹ̀ doje bọ̀ ọ, nitori ikore pọ́n : ẹ
wá, ẹ sọkalẹ; nitori ifunti kún, nitori awọn
ọpọ́n kún rekọja, nitori ìwa-buburu wọn
pọ̀.
14 Ọpọlọpọ, ọ̀pọlọpọ li afonifojì idajọ,
nitori ọjọ Oluwa kù si dẹ̀dẹ ni afonifojì
idajọ.
15 Orùn ati oṣupa yio ṣu òkunkun, ati
awọn irawọ̀ yio fà titàn wọn sẹhin.
16 Oluwa yio si ké ramùramù lati Sioni
wá, yio si fọ ohùn rẹ̀ jade lati Jerusalemu
wá ; awọn ọrun ati aiye yio si mì : ṣugbọn
Oluwa yio ṣe ãbò awọn ẹnia rẹ̀, ati agbara
awọn ọmọ Israeli.
17 Bẹ̃li ẹnyin o mọ̀ pe, Emi li Oluwa
Ọlọrun nyin, ti ngbe Sioni oke mimọ́ mi :
nigbana ni Jerusalemu yio jẹ mimọ́, awọn
alejo kì yio si là a kọja mọ.
18 Yio si ṣe li ọjọ na, awọn oke-nla yio
ma kán ọti-waini titún silẹ, awọn oke
kékèké yio ma ṣàn fun wara, ati gbogbo
odò Juda yio ma ṣan fun omi, orisun kan
yio si jade lati inu ile Oluwa wá, yio si rin
afonifojì Ṣittimu.
19 Egipti yio di ahoro, Edomu yio si di
aginju ahoro, nitori ìwa ipá si awọn ọmọ
Juda, nitoriti nwọn ti ta ẹjẹ̀ alaiṣẹ̀ silẹ ni
ilẹ wọn.
20 Ṣugbọn Juda yio joko titi lai, ati
Jerusalemu lati iran de iran.
21 Nitori emi o wẹ̀ ẹjẹ̀ wọn nù, ti emi
kò ti wẹnu : nitori Oluwa ngbe Sioni.

# AMOSI.

## ORI 1.

ỌRỌ Amosi, ẹniti o wa ninu awọn daran-
daran Tekoa, ti o ri niti Israeli li ọjọ
ọba Ussiah ọba Juda, ati li ọjọ Jeroboamu
ọmọ Joaṣi ọba Israeli, ọdun meji ṣãju isẹ̀lẹ
nì.
2 O si wipe, Oluwa yio bu jade lati
Sioni wá, yio si fọ̀ ohùn rẹ̀ lati Jerusalemu
wá ; ibùgbe awọn olùṣọ-agùtan yio si ṣọ̀fọ,
oke Karmeli yio si rọ.
3 Bayi li Oluwa wi ; nitori irekọja mẹta
ti Damasku, ati nitori mẹrin, emi kì o yi
iyà rẹ̀ kuro ; nitori nwọn ti fi ohunèlo irin
ipakà pa Gileadi :
4 Ṣugbọn emi o rán iná kan si ile Ha-
saeli, ti yio jo ãfin Benhadadi wọnni run.
5 Emi o ṣẹ ọpá idabu Damasku pẹlu,
emi o si ke ará pẹtẹlẹ Afeni kuro, ati ẹniti
o dì ọpá alade nì mu kuro ni ile Edeni :
awọn enia Siria yio si lọ si igbèkun si Kiri,
ni Oluwa wi.
6 Bayi li Oluwa wi ; nitori irekọja mẹta
ti Gasa, ati nitori mẹrin, emi kì o yi iyá rẹ̀
kuro ; nitori nwọn ti kó gbogbo igbèkun ni
igbèkun lọ, lati fi wọn le Edomu lọwọ.
7 Ṣugbọn emi o rán iná kan sara odi
Gasa, ti yio jo ãfin rẹ̀ wọnni run :
8 Emi o si ke ara Aṣdodi kuro, ati ẹniti
o di ọpá alade mu kuro ni Aṣkeloni, emi o

Digitized by Google

si yi ọwọ́ mi si Ekroni; iyokù ninu awọn ara Filistia yio ṣegbe, li Oluwa Ọlọrun wi.

9 Bayi li Oluwa wi; nitori irekọja mẹta ti Tire, ati nitori mẹrin: emi kì o yi iyà rẹ̀ kuro; nitori nwọn fi gbogbo igbèkun le Edomu lọwọ, nwọn kò si ranti majẹmu arakọnrin.

10 Ṣugbọn emi o rán iná kan sara odi Tire, ti yio jo ãfin rẹ̀ wọnni run.

11 Bayi li Oluwa wi; nitori irekọja mẹta ti Edomu, ati nitori mẹrin, emi kì o yi iyà rẹ̀ kuro; nitori o fi idà lepa arakọnrin rẹ̀, o si gbe gbogbo ãnu sọnù; ibinu rẹ̀ si nfaniya titi, o si pa ibinu rẹ̀ mọ titi lai.

12 Ṣugbọn emi o rán iná kan si Temani, ti yio jó afin Bosra wọnni run.

13 Bayi li Oluwa wi; nitori irekọja mẹta ti awọn ọmọ Ammoni, ati nitori mẹrin, emi kì o yi iyà rẹ̀ kuro; nitori nwọn ti là inu awọn aboyun Gileadi, ki nwọn le ba mu agbègbe wọn tobi:

14 Ṣugbọn emi o da iná kan ninu odi Rabba, yio si jó ãfin rẹ̀ wọnni run, pẹlu iho ayọ̀ li ọjọ ogun, pẹlu ijì li ọjọ ãjà:

15 Ọba wọn o si lọ si igbèkun, on ati awọn ọmọ-alade rẹ̀ pọ̀, li Oluwa wi.

## ORI 2.

BAYI li Oluwa wi; nitori irekọja mẹta ti Moabu, ati nitori mẹrin, emi kì o yi iyà rẹ̀ kuro; nitori o ti sun egungun ọba Edomu di ẽrú.

2 Ṣugbọn emi o rán iná kan sara Moabu, yio si jó ãfin Kirioti wọnni run: Moabu yio si kú pẹlu ariwo, pẹlu iho ayọ̀, ati pẹlu iro ipè:

3 Emi o si ké onidajọ kurò lãrin rẹ̀, emi o si pa gbogbo ọmọ-alade inu rẹ̀ pẹlu rẹ̀; li Oluwa wi.

4 Bayi li Oluwa wi; nitori irekọja mẹta ti Juda, ati nitori mẹrin, emi kì o yi iyà rẹ̀ kuro; nitori nwọn ti gàn ofin Oluwa, nwọn kò si pa aṣẹ rẹ̀ mọ, eke wọn si ti mu wọn ṣina, eyiti awọn baba wọn ti tẹle.

5 Ṣugbọn emi o rán iná kan sara Juda, yio si jó ãfin Jerusalemu wọnni run.

6 Bayi li Oluwa wi; nitori irekọja mẹta ti Israeli, ati nitori mẹrin, emi kì o yi iyà rẹ̀ kuro; nitori nwọn tà olododo fun fàdakà, ati talakà fun bàta ẹsẹ̀ mejeji;

7 Ti nmí hẹlẹ si erùpẹ ilẹ li ori talakà, ti o si yi ọ̀na ọlọkàn tutù po: ati ọmọ ati baba rẹ̀ nwọle tọ̀ wundia kan, lati bà orukọ mimọ́ mi jẹ.

8 Nwọn si dùbulẹ le aṣọ ti a fi lelẹ fun ògo lẹba olukuluku pẹpẹ, nwọn si mu ọti-waini awọn ti a yá, ni ile ọlọrun wọn.

9 Ṣugbọn mo pa ará Amori run niwaju wọn, giga ẹniti o dàbi giga igi kedari, on si le bi igi-oaku; ṣugbọn mo pa eso rẹ̀ run lati oke wá, ati egbò rẹ̀ lati isalẹ wá.

10 Emi mu nyin goke pẹlu lati ilẹ Egipti wá, mo si sìn nyin li ogoji ọdun là aginjù ja, lati ni ilẹ awọn Amori.

11 Mo si gbe ninu ọmọkọnrin nyin dide lati jẹ woli, ati ninu awọn ọdọmọkọnrin nyin lati jẹ Nasarite. Bẹ̃ ki o ri, ẹnyin ọmọ Israeli? li Oluwa wi.

12 Ṣugbọn ẹnyin fun awọn Nasarite ni ọti-waini mu, ẹ si paṣẹ fun awọn woli pe, Ẹ máṣe sọtẹlẹ.

13 Wò o, emi o tẹ̀ nyin mọlẹ, bi kẹkẹ́ ti o kún fun itì ti itẹ̀.

14 Nitorina sisá yio dẹtì fun ẹni yiyara, onipá kì yio si mu ipa rẹ̀ le, bẹ̃ni alagbara kì yio le gba ara rẹ̀ là.

15 Bẹ̃ni tafàtafà kì yio duro; ati ẹniti o yasẹ̀ kì yio le gbà ara rẹ̀ là: bẹ̃ni ẹniti ngùn ẹṣin kì yio gbà ara rẹ̀ là:

16 Ati ẹniti o gboiyà ninu awọn alagbara yio salọ ni ihòho li ọjọ na, li Oluwa wi.

## ORI 3.

EGBỌ́ ọ̀rọ yi ti Oluwa ti sọ si nyin, ẹnyin ọmọ Israeli, si gbogbo idile ti mo mú goke lati ilẹ Egipti wá, wipe,

2 Ẹnyin nikan ni mo mọ̀ ninu gbogbo idile aiye: nitorina emi o bẹ̀ nyin wò nitori gbogbo ẹ̀ṣẹ nyin.

3 Ẹni meji lè rìn pọ̀, bikòṣepe nwọn rẹ́?

4 Kiniun yio ké ramùramù ninu igbo, bi kò ni ohun ọdẹ! ọmọ kiniun yio ha ké jade ninu ihò rẹ̀, bi kò ri nkan mu?

5 Ẹiyẹ le lu okùn ni ilẹ, nibiti okùn didẹ kò gbe si fun u? okùn ha le ré kuro lori ilẹ, laijẹ pe o mu nkan rara?

6 A le fun ipè ni ilu, ki awọn enia má bẹru? tulasi ha le wà ni ilu, ki o má ṣepe Oluwa li o ṣe e?

7 Nitori Oluwa Ọlọrun kì o ṣe nkan kan, ṣugbọn o fi ohun ikọ̀kọ rẹ̀ hàn awọn woli iranṣẹ rẹ̀.

8 Kiniun ti ké ramùramù, tani kì yio bẹru? Oluwa Ọlọrun ti sọ̀rọ, tani lè ṣe aisọtẹlẹ?

9 Ẹ kede li ãfin Aṣdodu, ati li ãfin ni ilẹ Egipti, ki ẹ si wipe, Pè ara nyin jọ lori awọn oke nla Samaria, ki ẹ si wò irọkẹkẹ nla lãrin rẹ̀, ati inilara lãrin rẹ̀.

Digitized by Google

10 Nitori nwọn kò mọ̀ bi ati ṣe otitọ, li
Oluwa wi, nwọn ti kó ìwa-ipá ati ìwa-olè
jọ li ãfin wọn.
11 Nitorina, bayi li Oluwa Ọlọrun wi;
Ọta kan yio si wà yi ilẹ na ka; on o si sọ
agbara rẹ kalẹ kuro lara rẹ, a o si kó ãfin rẹ
wọnni.
12 Bayi li Oluwa wi; gẹgẹ bi oluṣọ-
agùtan iti gbà itan meji kuro li ẹnu kiniun,
tabi ẹlà eti kan; bẹ̃li a o mu awọn ọmọ
Israeli ti ngbe Samaria kuro ni igun akete,
ati ni aṣọ Damasku irọ̀gbọku.
13 Ẹ gbọ́, ẹ si jẹri si ile Jakobu, li
Oluwa Ọlọrun, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun wi,
14 Pe, li ọjọ ti emi o bẹ̀ irekọja Israeli
wò lara rẹ̀, emi o bẹ̀ awọn pẹpẹ Beteli wò
pẹlu: a o si ké iwo pẹpẹ kuro, nwọn o si
wó lulẹ.
15 Emi o si lù ile otutù pẹlu ile ẹ̃rùn;
ile ehín erin yio si ṣègbe, ile nla wọnni
yio si li opin, li Oluwa wi.

## ORI 4.

EGBỌ ọ̀rọ yi, ẹnyin ọmọ malu Baṣan, ti
o wà li oke nla Samaria, ti o nni tala-
kà lara, ti o ntẹ̀ alaini rẹ́, ti o nwi fun
oluwa wọn pe, Gbe wá, ki a si mu.
2 Oluwa Ọlọrun ti bura ninu iwà-mimọ́
rẹ̀, pe, Sa wò o, ọjọ wọnni yio de ba nyin,
ti on o fi ìwọ gbe nyin kuro, yio si fi ìwọ-
ẹja gbe iran nyin.
3 Ati ni ibi yiya odi wọnni li ẹnyin o ba
jade lọ, olukuluku niwaju rẹ̀ gan; ẹnyin o
si gbe ara nyin sọ si Harmona, li Oluwa wi.
4 Ẹ wá si Beteli, ki ẹ si dẹṣẹ: ẹ mu ire-
kọja nyin pọ̀ si i ni Gilgali; ẹ si mu ẹbọ
nyin wá li orowurọ̀, ati idamẹwa nyin lẹhìn
ọdun mẹta.
5 Ki ẹ si ru ẹbọ ọpẹ́ pẹlu iwukara, ẹ
kede, ki ẹ si fi ọrẹ atinuwa lọ̀: nitori bẹ̃li
ẹnyin fẹ́, ẹnyin ọmọ Israeli, li Oluwa Ọlọ-
run wi.
6 Emi pẹlu si ti fún nyin ni mimọ́ ehín
ni gbogbo ilu nyin, ati aini-onjẹ, ni ibùgbe
nyin gbogbo: sibẹ̀ ẹnyin kò yipadà sọdọ
mi, li Oluwa wi.
7 Ati pẹlu, emi ti fà ọwọ́ òjo sẹhìn kuro
lọdọ nyin, nigbati o kù oṣù mẹta si i fun
ikorè; emi si ti mu òjo rọ̀ si ilu kán, emi
kò si jẹ ki o rọ̀ si ilu miràn: o rọ̀ si apa-
kan, ibiti kò gbe rọ̀ si si rọ.
8 Bẹ̃ni ilu meji tabi mẹta nrìn lọ si ilu
kan, lati mu omi: ṣugbọn kò tẹ́ wọn
lọrùn: sibẹ̀ ẹnyin kò ti ipadà sọdọ mi, li
Oluwa wi.
9 Mo ti fi irẹ̀danù ati imúwòdú lù nyin:
nigbati ọgbà nyin ati ọgbà-àjara nyin, ati
igi ọ̀pọtọ́ nyin, ati igi olifi nyin npọ̀ si i,
kòkoro jẹ wọn run; sibẹ̀ ẹnyin kò ti ipadà
sọdọ mi, li Oluwa wi.
10 Mo ti rán ajàkalẹ-arùn si ãrin nyin,
gẹgẹ bi ti Egipti: awọn ọdọmọkọnrin nyin
li emi si ti fi idà pa, nwọn si ti kó ẹṣin
nyin ni igbèkun pẹlu; mo si ti jẹ ki õrùn
ibùdo nyin bù soke wá si imú nyin: sibẹ̀
ẹnyin kò ti ipadà sọdọ mi, li Oluwa wi.
11 Mo ti bì ṣubu ninu nyin, bi Ọlọrun
ti bì Sodomu on Gomorra ṣubu, ẹnyin si
dàbi ogúná ti a fà yọ kuro ninu ijoná: sibẹ̀
ẹnyin kò ti ipadà sọdọ mi, li Oluwa wi.
12 Nitorina, bayi li emi o ṣe si ọ, iwọ
Israeli: ati nitoriti emi o ṣe eyi si ọ, mura
lati pade Ọlọrun rẹ, iwọ Israeli.
13 Nitori sa wò o, ẹniti o dá awọn oke
nla, ti o si dá afẹ̃fẹ, ti o si sọ fun enia
ohun ti erò inu rẹ̀ jasi, ti o sọ owurọ̀ di
òkunkun, ti o si tẹ̀ ibi giga aiye mọlẹ,
Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀.

## ORI 5.

EGBỌ́ ọ̀rọ yi ti emi gbe soke si nyin, ani
ohùnréré ẹkun, ẹnyin ile Israeli.
2 Wundia Israeli ti ṣubu; kì yio dide
mọ: a kọ̀ ọ silẹ lori ilẹ rẹ̀; kò si ẹniti yio
gbe e dide.
3 Nitori bayi li Oluwa Ọlọrun wi; Ilu
ti o jade lọ li ẹgbẹrun yio ṣikù ọgọrun;
eyiti o si jade lọ li ọgọrun yio ṣikù mẹwa,
fun ile Israeli.
4 Nitori bayi li Oluwa wi fun ile Israeli,
ẹ wá mi, ẹnyin o si yè?
5 Ṣugbon ẹ máṣe wá Beteli, bẹ̃ni ki ẹ
má wọ̀ inu Gilgali lọ, ẹ má si rekọja lọ si
Beerṣeba: nitori lõtọ Gilgali yio lọ si igbè-
kun, Beteli yio si di asan.
6 Ẹ wá Oluwa, ẹnyin o si yè; ki o má
ba gbile bi iná ni ile Josefu, a si jó o run,
ti kì o fi si ẹnikan lati pá a ni Beteli.
7 Ẹnyin ti ẹ sọ idájọ di iwọ, ti ẹ si kọ̀
ododo silẹ li aiye.
8 Ẹ wá ẹniti o dá irawọ̀ meje nì ati Ori-
oni, ti o si sọ ojiji ikú di owurọ̀, ti o si fi
oru mu ọjọ ṣokùnkun: ti o pè awọn omi
okun, ti o si tú wọn jade soju aiye: Olu-
wa li orukọ rẹ̀:
9 Ti o mu iparun kọ manà sori alagbara,
tobẹ̃ ti iparun yio wá si odi agbara.
10 Nwọn korira ẹniti nbaniwi li ẹnu
bodè, nwọn si korira ẹniti nsọ otitọ.
11 Nitorina niwọ̀n bi itẹ̀mọlẹ nyin ti wà
lori talakà, ti ẹnyin si gba ẹrù alikama
lọwọ rẹ̀: ẹnyin ti fi okuta ti a gbẹ́ kọ́ ile,

Digitized by Google

ṣugbọn ẹ kì o gbe inu wọn; ẹnyin ti gbìn
ọgbà àjara daradara, ṣugbọn ẹ kì o mu ọti-
waini wọn.
12 Nitori mo mọ̀ onirũru irekọja nyin,
ati ẹ̀ṣẹ nla nyin: nwọn npọ́n olododo loju,
nwọn ngbà owo abẹ̀tẹlẹ, nwọn si nyi awọn
talakà si apakan ni bodè, kuro ninu are
wọn.
13 Nitorina, ẹni-oye yio dakẹ nigbana;
nitori akòko ibi ni.
14 Ẹ ma wá ire, kì isi iṣe ibi, ki ẹ ba le
yè; bẹ̃ni Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun,
yio si pẹlu nyin, bi ẹnyin ti wi.
15 Ẹ korira ibi, ẹ si fẹ́ ire, ki ẹ si fi ida-
jọ gunlẹ ni bodè; boya Oluwa Ọlọrun
awọn ọmọ-ogun yio ṣe ojurere si iyokù
Josefu.
16 Nitorina Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-
ogun, ani Oluwa wi bayi pe, Ẹkun yio wà
ni gbogbo ita; nwọn o si ma wi ni gbogbo
ọ̀popó ọna pe, Ã! ã! nwọn o si pè agbẹ̀ si
iṣọ̀fọ, ati iru awọn ti o gbọ́n lati pohùnrére
si isọkún.
17 Ati ni gbogbo ọ̀gba àjara ni isọkún
yio gbe wà: nitori emi o kọja lãrin rẹ, li
Oluwa wi.
18 Egbe ni fun ẹnyin ti ẹ nfẹ́ ọjọ Oluwa!
kili eyi o jasi fun nyin? ọjọ Oluwa òkun-
kun ni, kì isi iṣe imọlẹ.
19 Gẹgẹ bi enia ti o sa fun kiniun, ti
beari si pade rẹ̀; tabi ti o wọ̀ inu ile, ti o si
fi ọwọ́ rẹ̀ tì lara ogiri, ti ejò si bù u jẹ.
20 Ọjọ Oluwa kì o ha ṣe òkunkun laiṣe
imọlẹ? ani òkunkun biribiri, laisi imọlẹ
ninu rẹ̀?
21 Mo korira, mo si kẹgàn ọjọ asè nyin,
emi kì o si gbõrùn ọjọ ajọ ọ̀wọ nyin.
22 Bi ẹnyin tilẹ rú ẹbọ sisun ati ẹbọ jijẹ
nyin si mi, emi kì o si gbà wọn: bẹ̃ni emi
ki yio nani ẹbọ ọpẹ́ ẹran abọ́pa nyin.
23 Mu ariwo orin rẹ kuro lọdọ mi; nito-
ri emi kì o gbọ́ iró adùn fioli rẹ.
24 Ṣugbọn jẹ ki idajọ ki o ṣàn silẹ bi
omi, ati ododo bi iṣàn omi nla.
25 Ẹnyin ha ti rubọ si mi, ẹ ha ti ta mi
lọrẹ li aginjù li ogoji ọdun, ẹnyin ile
Israeli.
26 Ṣugbọn ẹnyin ti rù agọ Moloku ati
Kiuni nyin, awọn ere nyin, irawọ̀ òriṣa
nyin, ti ẹ ṣe fun ara nyin.
27 Nitorina, emi o mu ki ẹ lọ si igbèkun
rekọja Damasku, li Oluwa wi, Ọlọrun
awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀.

## ORI 6.

EGBE ni fun ẹniti ara rọ̀ ni Sioni, ati
awọn ti o gbẹkẹ̀le oke nla Samaria,
awọn ti a pè ni ikini ninu awọn orilẹ-ède,
awọn ti ile Israeli tọ̀ wá!
2 Ẹ kọja si Kalne, si wò; ẹ si ti ibẹ̀ lọ
si Hamati nla: lẹhin na ẹ sọ̀kalẹ lọ si Gati
ti awọn Filistini: nwọn ha sian jù ilẹ ọba
wọnyi lọ? tabi agbègbe wọn ha tobi jù
agbègbe nyin lọ?
3 Ẹnyin ti o sún ọjọ ibi siwaju, ti ẹ si
mu ibùgbe ìwa-ipá sunmọ tòsi;
4 Awọn ti o ndùbulẹ lori akete ehin-erin,
ti nwọn si nnà ara wọn lori irọ̀gbọku wọn,
ti nwọn njẹ ọdọ-agùtan inu agbo, ati ẹgbọ̀-
rọ malu inu agbo;
5 Ti nwáhùn si iró orin fioli, ti nwọn si
nṣe ohun-ikọrin fun ara wọn, bi Dafidi;
6 Awọn ti nmuti ninu ọpọ́n waini, ti
nwọn si nfi olori ororo kun ara wọn; ṣu-
gbọn nwọn kò banujẹ nitori ipọnju Josefu.
7 Nitorina awọn ni o lọ si igbèkun pẹlu
awọn ti o ti kọ́ lọ si igbèkun; àse awọn ti
nṣe aṣeleke li a o mu kuro,
8 Oluwa Ọlọrun ti fi ara rẹ̀ bura, li Olu-
wa Ọlọrun awọn ọmọ ogun wi, Emi korira
ọlanla Jakobu, mo si korira ãfin rẹ̀: nito-
rina li emi o ṣe fi ilu na, ati ohun gbogbo
ti o wà ninu rẹ̀ tọrẹ.
9 Yio si ṣe, bi enia mẹwa li o ba kù
ninu ile kan, nwọn o si kú.
10 Ati arakọnrin rẹ̀, ati ẹniti o nfi i
joná, lati kó egungun wọnni jade kuro
ninu ile, yio gbe e, yio si bi ẹniti o wà li
ẹba ile lere pe, O ha tun kù ẹnikan pẹlu
rẹ? On o si wipe, Bẹ̃kọ̀. Nigbana li on o
wipe, Pa ẹnu rẹ mọ: nitoripe awa kò gbọ-
dọ da orukọ Oluwa.
11 Nitori kiyesi i, Oluwa paṣẹ, yio si fi
iparun kọlù ile nla na, ati sisán kọlù ile
kékèké.
12 Ẹṣin ha le ma sure lori apata? ẹni-
kan ha le fi akọ malu ṣiṣẹ plau nibẹ̀? nito-
riti ẹnyin ti yi idajọ dà si oró, ati eso odo-
do dà si iwọ:
13 Ẹnyin ti nyọ̀ si ohun asan, ti nwipe,
Nipa agbara ara wa kọ́ li awa fi gbà iwo
fun ara wa?
14 Ṣugbọn, kiyesi i, emi o gbe orilẹ-ède
kan dide si nyin, ẹnyin ile Israeli, li Olu-
wa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun wi; nwọn o si
pọ́n nyin loju lati iwọle Hamati, titi de
odò pẹ̀tẹlẹ.

Digitized by Google

## ORI 7.

BAYI li Oluwa Ọlọrun ti fi hàn mi; si
wò o, o dá ẽṣú ni ibẹrẹ irú-soke idàgba
ikẹhin, si wò o, idàgba ikẹhìn lẹhìn ike-
kuro ti ọba nì.
2 O si ṣe, ti nwọn jẹ koriko ilẹ na tan,
nigbana ni mo wipe, Oluwa Ọlọrun, darijì,
emi bẹ̀ ọ: Jakobu yio ha ṣe le dide? nitori
ẹnikekere li on.
3 Oluwa ronupiwàda nitori eyi: kì yio
ṣe, li Oluwa wi.
4 Bayi li Oluwa Ọlọrun ti fi hàn mi: si
wò o, Oluwa Ọlọrun pè lati fi iná jà, o si
jó ibú nla nì run, o si jẹ apakan run.
5 Nigbana ni mo wipe, Oluwa Ọlọrun,
dawọ duro, emi bẹ̀ ọ: Jakobu yio ha ṣe le
dide? nitori ẹnikekere li on.
6 Oluwa ronupiwàda nitori eyi: Eyi pẹ-
lu kì yio ṣe, li Oluwa Ọlọrun wi.
7 Bayi li on fi hàn mi: si wò o, Oluwa
duro lori odi kan, ti a fi okùn-ìwọn ti o
run mọ, ti on ti okùn-ìwọn ti o run li ọwọ́
rẹ̀.
8 Oluwa si wi fun mi pe, Amosi, kini
iwọ ri? Emi si wipe, Okùn-ìwọn kan ti o
run ni. Nigbana ni Oluwa wipe, Wò o,
emi o fi okùn-ìwọn rirun kan le ilẹ lãrin
Israeli enia mi: emi kì yio si tun kọja
lọdọ wọn mọ:
9 Ibi giga Israeli wọnni yio si di ahoro:
ati ibi mimọ́ Israeli wọnni yio di ahoro;
emi o si fi idà dide si ile Jeroboamu.
10 Nigbana ni Amasiah, alufa Beteli
ranṣẹ si Jeroboamu ọba Israeli, wipe, Amo-
si ti ditẹ̀ si ọ lãrin ile Israeli: ilẹ kò si le
gba gbogbo ọ̀rọ rẹ̀.
11 Nitori bayi li Amosi wi, Jeroboamu
yio ti ipa idà kú, nitõtọ Israeli li a o si fà
lọ si igbèkun kuro ni ilẹ rẹ̀.
12 Amasiah sọ fun Amosi pẹlu pe, Iwọ
ariran, lọ, salọ si ilẹ Juda, si ma jẹun nibẹ̀,
si ma sọtẹlẹ nibẹ̀:
13 Ṣugbọn máṣe sọtẹlẹ̀ mọ ni Beteli:
nitori ibi mimọ́ ọba ni, ãfin ọba si ni.
14 Nigbana ni Amosi dahùn, o si wi fun
Amasiah pe, Emi ki iṣe woli ri, bẽni emi
kì iṣe ọmọ woli, ṣugbọn olùṣọ-agùtan li
emi ti iṣe ri, ati ẹniti iti ma ká eso ọpọtọ:
15 Oluwa si mu mi, bi mo ti ntọ̀ agbo-
ẹran lẹhìn, Oluwa si wi fun mi pe, Lọ, sọ-
tẹlẹ̀ fun Israeli enia mi.
16 Njẹ nisisiyi, iwọ gbọ́ ọ̀rọ Oluwa:
Iwọ wipe, Máṣe sọtẹlẹ̀ si Israeli, má si jẹ
ki ọ̀rọ rẹ kán silẹ si ile Isaaki.
17 Nitorina bayi li Oluwa wi; Obirin
rẹ yio di panṣagà ni ilu, ati awọn ọmọ rẹ
ọkọnrin ati awọn ọmọ rẹ obirin, yio ti ipa
idà ṣubu; ilẹ rẹ li a o si fi okùn pin; iwọ
o si kú ni ilẹ aimọ́: nitõtọ, a o si kó Israeli
lọ ni igbèkun kuro ni ilẹ rẹ̀.

## ORI 8.

BAYI li Oluwa Ọlọrun ti fi hàn mi: si
kiyesi i, agbọ̀n eso ẹrùn kan.
2 On si wipe, Amosi, kili ohun ti iwọ ri?
Emi si wipe, Agbọ̀n eso ẹrùn ni. Nigbana
li Oluwa wi fun mi pe, Opin de si Israeli
enia mi; emi kì yio tún kọja lọdọ wọn mọ.
3 Orin inu tempili yio si jẹ hihu li ọjọ
na, li Oluwa Ọlọrun wi: okú pupọ̀ ni yio
wà ni ibi gbogbo; nwọn o ma fi idakẹ jù
wọn sode.
4 Ẹ gbọ́ eyi, ẹnyin ti ngbe awọn alaini
mì, lati sọ awọn talakà ilẹ na di alaini,
5 Ti nwipe, Nigbawo ni oṣù titún yio
pari, ki awa ba le ta ọkà? ati ọjọ isimi, ki
awa ba le ṣi alikama silẹ, ki a si ṣe ìwọn
efà kere, ati ìwọn ṣekeli tobi, ki a si ma fi
ẹ̀tan yi ìwọn padà?
6 Ki awa le fi fàdakà rà talakà, ati bàta
ẹsẹ̀ mejeji rà alaini, ki a si tà eyiti o dànu
ninu alikama?
7 Oluwa ti bura nipa ọlanla Jakobu pe,
Nitõtọ emi kì yio gbàgbe ọkan ninu iṣẹ
wọn.
8 Ilẹ na kì yio ha warìri nitori eyi, ati
olukuluku ẹniti o ngbe inu rẹ̀ kì yio ha
ṣọ̀fọ? yio si rú soke patapata bi kikún omi;
a o si tì i jade, a o si tẹ̀ ẹ rì, gẹgẹ bi odò
Egipti.
9 Yio si ṣe li ọjọ na, li Oluwa Ọlọrun
wi; emi o si mu ki õrùn ki o wọ̀ lọsan,
emi o si mu aiye ṣu òkunkun li òsan
gangan:
10 Emi o si yi àse nyin padà si ọ̀fọ, ati
orin nyin gbogbo si ohùn-rére ẹkún: emi
o si mu aṣọ ọ̀fọ wá si ẹgbẹ̀ gbogbo, ati pipá
ori, si gbogbo ori; emi o si ṣe e ki o dàbi
iṣọ̀fọ fun ọmọ kanṣoṣo ti a bi; ati opin rẹ̀
bi ọjọ kikorò.
11 Kiyesi i, ọjọ na de, li Oluwa Ọlọrun
wi, emi o rán iyàn wá si ilẹ na, kì iṣe iyàn
onjẹ, tabi ongbẹ fun omi, ṣugbọn iyàn
gbigbọ́ ọ̀rọ Oluwa:
12 Nwọn o si ma rìn kiri lati okun de
okun, ati lati ariwa ani titi de gabasi,
nwọn o sare siwá sẹhìn lati wá ọ̀rọ Oluwa,
nwọn kì yio si ri.
13 Li ọjọ na li awọn arẹwà wundia, ati
awọn ọdọmọkọnrin yio daku fun ongbẹ.
14 Awọn ti o fi ẹ̀ṣẹ Samaria bura, ti

Digitized by Google

nwọn si wipe, Iwọ Dani, ọlọrun rẹ mbẹ
lãyè! ati ọ̀na Beerṣeba mbẹ lãyè! ani nwọn
o ṣubu, nwọn kì yio si tún dide mọ.

## ORI 9.

MO ri Oluwa o duro lori pẹpẹ: o si wipe,
Lù itẹrigbà ilẹ̀kun, ki awọn ò̀po ki o
le mì: si ṣá wọn li ori, gbogbo wọn; emi
o si fi idà pa ẹni ikẹhìn wọn: ẹniti o sá
ninu wọn, kì yio salọ gbe; ati ẹniti o sa
asalà ninu wọn li a kì yio gbàla.
2 Bi nwọn tilẹ wà ilẹ lọ si ọrun-apadi,
lati ibẹ̀ li ọwọ́ mi yio ti tẹ̀ wọn; bi nwọn
tilẹ gùn okè ọrun lọ; lati ibẹ̀ li emi o ti
mu wọn sọ̀kalẹ:
3 Ati bi nwọn tilẹ fi ara wọn pamọ li
ori oke Karmeli; emi o wá wọn ri, emi o
si mu wọn kuro nibẹ̀; ati bi a tilẹ fi wọn
pamọ kuro niwaju mi ni isàlẹ okun; lati
ibẹ̀ na li emi o ti paṣẹ fun ejò nì, on o si
bù wọn jẹ:
4 Ati bi nwọn tilẹ lọ si igbèkun niwaju
awọn ọta wọn, lati ibẹ̀ wá li emi o ti paṣẹ
fun idà, on o si pa wọn: emi a si tẹ̀ oju
mi mọ wọn lara fun ibi, kì isi ṣe fun ire.
5 Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun li ẹniti
o si fi ọwọ́ kan ilẹ na, yio si di yiyọ́, gbo-
gbo awọn ti o ngbe inu rẹ̀ yio si ṣọ̀fọ: yio
si rú soke patapata bi kikun omi: a o si tẹ̀
ẹ rì, bi odò Egipti.
6 On li ẹniti o kọ́ itẹ́ rẹ̀ ninu awọn ọrun,
ti o si fi ipilẹ rẹ̀ sọlẹ ni ilẹ aiye: ẹniti o pè
awọn omi okun, ti o si tú won jade si ori
ilẹ aiye: Oluwa li orukọ rẹ̀.
7 Ẹnyin kò ha dàbi awọn ọmọ Etiopia si
mi, Ẹnyin ọmọ Israeli? li Oluwa wi. Emi
kò ha ti mu Israeli goke ti ilẹ Egipti jade
wá? ati awọn Filistini lati ilẹ Kaftori, ati
awọn ara Siria lati Kiri.
8 Kiyesi i, Oluwa Ọlọrun mbẹ lara ilẹ
ọba ti o kún fun ẹ̀ṣẹ, emi o si pa a run ku-
ro lori ilẹ; ṣugbọn emi kì yio pa ile Jako-
bu run tan patapata, li Oluwa wi.
9 Wò o, nitori emi o paṣẹ, emi o si kù
ile Israeli ninu awọn orilẹ-ède, bi a ti kù
ọkà ninu kọ̀nkọsọ, ṣugbọn woro kikini kì
yio bọ́ sori ilẹ.
10 Gbogbo awọn ẹlẹṣẹ ninu enia mi yio
ti ipa idà kú, ti nwipe, Ibi na kì yio le wa
ba, bẹ̃ni kì yio ba wa lojiji.
11 Li ọjọ na li emi o gbe agọ Dafidi ti o
ṣubu ró, emi o si dí ẹya rẹ̀; emi o si gbe
ahoro rẹ̀ soke, emi o si kọ́ ọ bi ti ọjọ
igbani:
12 Ki nwọn le ni iyokù Edomu ni iní,
ati ti gbogbo awọn keferi, ti a pè nipa oru-
kọ mi, li Oluwa ti o nṣe eyi wi.
13 Kiyesi i, ojọ na de, li Oluwa wi, ti
ẹniti ntulẹ yio le ẹniti nkorè bá, ati ẹniti o
ntẹ̀ eso àjara yio le ẹniti o nfunrùgbin bá;
awọn oke-nla yio si kán ọti-waini didùn silẹ,
gbogbo oke kékèké yio si di yiyọ́.
14 Emi o si tun mu igbèkun Israeli enia
mi padà bọ̀, nwọn o si kọ́ ahoro ilu wọnni,
nwọn o si ma gbe inu wọn; nwọn o si gbin
ọgbà-àjara, nwọn o si mu ọti-waini wọn;
nwọn o ṣe ọgbà pẹlu, nwọn o si jẹ eso inu
won.
15 Emi o si gbìn wọn si ori ilẹ wọn, a
kì yio si fà wọn tu mọ kuro ninu ilẹ wọn,
ti mo ti fi fun wọn, li Oluwa Ọlọrun rẹ wi.

---

# OBADIAH.

IRAN ti Obadiah. Bayi ni Oluwa Ọlọrun
wi niti Edomu; Awa ti gbọ́ ihìn kan
lati ọdọ Oluwa wá, a si ti rán ikọ̀ kan si
ãrin awọn keferi, Ẹ dide, ẹ si jẹ ki a dide
ogun si i.
2 Kiyesi i, mo ti sọ iwọ di kekere larin
awọn keferi: iwọ di gigàn lọpọlọpọ.
3 Irera aiya rẹ ti tàn ọ jẹ, iwọ ti ngbe
inu pàlapála apáta, ibugbe ẹniti o ga: ti o
nwi li lọkàn rẹ̀ pe, Tani yio mu mi sọkalẹ?
4 Bi iwọ tilẹ gbe ara rẹ ga bi idì, ati bi
iwọ tilẹ tẹ́ itẹ rẹ sãrin awọn irawọ, lati ibẹ
li emi o ti sọ̀ ọ kalẹ, ni Oluwa wi.
5 Bi awọn olè tọ̀ ọ wá, bi awọn ọlọṣà
li oru, (bawo li a ti ke ọ kuro!) nwọn kì
yio ha jale titi nwọn fi ni to? bi awọn
aka-eso-ajara wá sọdọ rẹ, nwọn kì yio ha fi
ẽṣẹ́ diẹ silẹ?
6 Bawo li a ti ṣawari awọn nkan Esau!
bawo li a ti wá awọn ohun ikọkọ rẹ̀ jade!

Digitized by Google

7 Gbogbo awọn ẹni imulẹ rẹ ti mu ọ de
opin ilẹ rẹ: awọn ti nwọn ti wà li alafia
pẹlu rẹ ti tàn ọ jẹ, nwọn si bori rẹ; awọn
ti o jẹ onjẹ rẹ ti fi ọgbẹ́ si abẹ rẹ: oye kò
si ninu rẹ̀.
8 Oluwa wipe, li ọjọ na ki emi o run
awọn ọlọgbọn kuro ni Edomu, ati imoye
kuro li oke Esau?
9 Awọn alagbara rẹ yio si bẹ́ru, iwọ
Temani, nitori ki a le ke olukuluku ti ori
oke Esau kuro nitori ipania.
10 Nitori ìwa-ipa si Jakobu arakọnrin
rẹ itiju yio bò ọ, a o si ke ọ kuro titi lai.
11 Ni ọjọ ti iwọ duro li apa keji, ni ọjọ
ti awọn alejo kó awọn ogun rẹ̀ ni igbèkun
lọ, ti awọn ajeji si wọ inu ibode rẹ̀, ti nwọn
si ṣẹ keké lori Jerusalemu, ani iwọ wà bi
ọkan ninu wọn.
12 Ṣugbọn iwọ kì ba ti ṣiju wo ọjọ ara-
kọnrin rẹ ni ọjọ ti on di ajeji; bẽni iwọ kì
ba ti yọ̀ lori awọn ọmọ Juda ni ọjọ iparun
wọn; bẽni iwọ kì ba ti sọ̀rọ irera ni ọjọ
wahala.
13 Iwọ kì ba ti wọ inu ibode awọn enia
mi lọ li ọjọ ijàmú wọn; nitotọ, iwọ kì ba
ti ṣiju wo iponju wọn li ọjọ ijàmú wọn,
bẽni iwọ kì ba ti gbe ọwọ́ le ohun ini wọn
li ọ̀jọ ijàmú wọn.
14 Bẽni iwọ kì ba ti duro ni ikorita lati
ké awọn tirẹ̀ ti o ti salà kuro; bẽni iwọ
kì ba ti sé awọn tirẹ̀ ti o kù li ọjọ wahala
mọ.
15 Nitori ọjọ Oluwa kù si dẹdẹ sori
gbogbo awọn keferi: bi iwọ ti ṣe, bẽli a
o si ṣe si ọ: ẹsan rẹ yio si yipada sori
ara rẹ.
16 Nitori bi ẹnyin ti mu lori oke mimọ́
mi, bẽni gbogbo awọn keferi yio ma mu
titi, nitõtọ nwọn o mu, nwọn o si gbemì,
nwọn o si wà bi ẹnipe nwọn kò ti si.
17 Ṣugbọn igbala yio wà lori oke Sioni,
yio si jẹ mimọ́, awọn ara ile Jakobu yio si
ni ini wọn.
18 Ile Jakobu yio si jẹ iná, ati ile Josefu
ọwọ́-iná, ati ile Esau fun akeku koriko,
nwọn o sì ràn ninu wọn, nwọn o si run
wọn; kì yio si sí ẹniti yio kù ni ile Esau:
nitori Oluwa ti wi i.
19 Awọn ara gusu yio ni oke Esau;
awọn ti pẹtẹlẹ yio si ni awọn ara Filistia:
nwọn o si ni oko Efraimu, ati oko Sama-
ria: Benjamini yio si ni Gileadi.
20 Ati igbèkun ogun yi, ti awọn ọmọ
Israeli ti o wà larin awọn ara Kenaani,
titi de Sarefati; ati igbèkun Jerusalemu
ti o wà ni Sefaradi, yio ni awọn ilu nla
gusu.
21 Awọn olugbala yio si goke Sioni wá
lati ṣe idajọ oke Esau; ijọba na yio si jẹ
ti Oluwa.

---

# JONA.

## ORI 1.

NJẸ ọ̀rọ Oluwa tọ̀ Jona ọmọ Amittai wá,
wipe,
2 Dide, lọ si Ninefe, ilunla nì, ki o si
kigbe si i; nitori ìwa buburu wọn goke
wá iwaju mi.
3 Ṣugbọn Jona dide lati sá lọ si Tarṣiṣi
kuro niwaju Oluwa, o si sọkalẹ lọ si
Joppa; o si ri ọkọ̀ kan ti nlọ si Tarṣiṣi:
bẽli o sanwo ọkọ, o si sọkalẹ sinu rẹ̀, lati
ba wọn lọ si Tarṣiṣi kuro niwaju Oluwa.
4 Ṣugbọn Oluwa rán ẹfufu nla jade si
oju okun, ijì lile si wà ninu okun, tobẽ ti
ọkọ̀ na dabi ẹnipe yio fọ.
5 Nigbana ni awọn atukọ̀ bẹ̀ru, oluku-
luku si kigbe si ọlọrun rẹ̀, nwọn ko ẹrù
ti o wà ninu ọkọ dà sinu okun, lati mu
u fẹrẹ. Ṣugbọn Jona sọkalẹ lọ si ẹ̀gbẹ́
ọkọ̀; o si dubulẹ sùn wọra.
6 Bẽli olori-ọkọ̀ tọ̀ ọ wá, o si wi fun u
pe, Kini iwọ rò, iwọ olõrun? dide, kepe
Ọlọrun rẹ, boya Ọlọrun yio ro ti wa, ki
awa ki o má bà ṣegbe.
7 Olukuluku wọn si wi fun ẹgbẹ rẹ̀ pe,
Wá, ẹ si jẹ ka ṣẹ keké, ki awa ki o le mọ̀
itori tani buburu yi ṣe wá sori wa. Bẽni
nwọn ṣẹ keké, keké si mu Jona.
8 Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Sọ fun
wa, awa bẹ̀ ọ, nitori ti tani buburu yi
ṣe wá sori wa? kini iṣẹ rẹ? nibo ni iwọ

Digitized by Google

si ti wá? orukọ ilu rẹ? orilẹ-ède wo ni
iwọ si iṣe?
9 On si wi fun wọn pe, Heberu li emi;
mo si bẹ̀ru Oluwa, Ọlọrun ọrun, ti o dá
okun ati iyangbẹ ilẹ.
10 Nigbana ni awọn ọkọnrin na bẹ̀ru
gidigidi, nwọn si wi fun u pe, Ẽṣe ti iwọ
fi ṣe eyi? nitori awọn ọkọnrin na mọ̀ pe
o sá kuro niwaju Oluwa, nitori on ti sọ
fun wọn.
11 Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Kini
ki a ṣe si ọ, ki okun le dakẹ fun wa?
nitori okun ru, o si jà ẹfufu lile.
12 On si wi fun wọn pe, Ẹ gbe mi, ki
ẹ si sọ mi sinu okun; bẹ̃li okun yio si
dakẹ fun nyin: nitori emi mọ̀ pe nitori
mi ni ẹfufu lile yi ṣe de bá nyin.
13 Ṣugbọn awọn ọkọnrin na wà kikan
lati mu ọkọ̀ wá si ilẹ; ṣugbọn nwọn kò le
ṣe e: nitori ti okun ru, o si ja ẹfufu lile
si wọn.
14 Nitorina nwọn kigbe si Oluwa nwọn
si wi pe, Awa bẹ̀ ọ, Oluwa, awa bẹ̀ ọ, máṣe
jẹ ki awa ṣegbe nitori ẹmi ọkọnrin yi, má
si ka ẹjẹ alaiṣẹ si wa li ọrùn: nitori iwọ,
Oluwa, ti ṣe bi o ti wù ọ.
15 Bẹ̃ni nwọn gbe Jona, ti nwọn si sọ
ọ sinu okun: okun si dẹkun riru rẹ̀.
16 Nigbana ni awọn ọkọnrin na bẹ̀ru
Oluwa gidigidi, nwọn si rubọ si Oluwa,
nwọn si jẹ́ ẹ̀jẹ́.
17 Ṣugbọn Oluwa ti pese ẹja nla kan
lati gbe Jona mì. Jona si wà ninu ẹja na
li ọsan mẹta ati oru mẹta.

## ORI 2.

NIGBANA ni Jona gbadura si Oluwa
Ọlọrun rẹ̀ lati inu ẹja na wá,
2 O si wipe, Emi kigbe nitori ipọnju
mi si Oluwa, on si gbohùn mi; mo kigbe
lati inu ipo-okú, iwọ si ti gbohùn mi.
3 Nitoriti iwọ ti sọ mi sinu ibu, larin
okun; iṣàn omi si yi mi kakiri; gbogbo
bibì omi ati riru omi rẹ kọja lori mi.
4 Nigbana ni mo wipe, A ta mi nù
kuro niwaju rẹ; ṣugbọn sibẹ emi o tun
ma wo iha tempili mimọ́ rẹ.
5 Omi yi mi kakiri, ani titi de ọkàn;
ibu yi mi kakiri, a fi koriko-odò wé mi
lori.
6 Emi sọkalẹ lọ si isalẹ awọn oke nla;
ilẹ aiye pẹlu idenà rẹ̀ wà yi mi ka titi:
ṣugbọn iwọ ti mu ẹmi mi wá soke lati inu
ibú wá, Oluwa Ọlọrun mi.
7 Nigbati o rẹ ọkàn mi ninu mi, emi
ranti Oluwa: adura mi si wá sọdọ rẹ sinu
tempili mimọ́ rẹ.
8 Awọn ti nkiyesi eke asan kọ̀ ãnu ara
wọn silẹ.
9 Ṣugbọn emi o fi ohùn idupẹ rubọ si ọ;
emi o san ẹjẹ́ ti mo ti jẹ. Ti Oluwa ni
igbala.
10 Oluwa si sọ fun ẹja na, o si pọ̀ Jona
sori ilẹ gbigbẹ.

## ORI 3.

ỌRỌ Oluwa si tọ̀ Jona wá lẹ̃keji, wipe,
2 Dide, lọ si Ninefe, ilu nla nì, ki o
si kede si i ikede ti mo sọ fun ọ.
3 Jona si dide, o si lọ si Ninefe, gẹgẹbi
ọ̀rọ Oluwa. Ninefe si jẹ ilu nla gidigidi
tó irin ijọ mẹta.
4 Jona si bẹrẹsi wọ inu ilu na lọ ni irin
ijọ kan, o si kede, o si wipe, Niwọn ogoji
ọjọ si i, a o bì Ninefe wo.
5 Awọn enia Ninefe si gba Ọlọrun gbọ́,
nwọn si kede awẹ̀, nwọn si wọ aṣọ ọ̀fọ, lati
agbà wọn titi de kekere wọn.
6 Ọrọ na si de ọdọ ọba Ninefe, o si dide
kuro lori itẹ rẹ̀, o si bọ aṣọ igunwa rẹ̀ kuro
lara rẹ̀, o si daṣọ ọ̀fọ bora, o si joko ninu
ẽru.
7 O si kede rẹ̀, o si wi pe ki a là Ninefe
ja nipa aṣẹ ọba, ati awọn agbagbà rẹ̀ pe,
Máṣe jẹ ki enia, tabi ẹranko, ọwọ-ẹran tabi
agbo-ẹran, tọ́ ohunkohun wò: má jẹ ki
wọn jẹun, má jẹ ki wọn mu omi.
8 Ṣugbọn jẹ ki enia ati ẹranko fi aṣọ ọ̀fọ
bora, ki nwọn si kigbe kikan si Ọlọrun: si
jẹ ki nwọn yipada, olukuluku kuro li ọ̀na
ibi rẹ̀, ati kuro ni iwa agbara ti o wà lọwọ
wọn.
9 Tani le mọ̀ bi Ọlọrun yio yipada ki o
si ronupiwada, ki o si yipada kuro ni ibinu
gbigbona rẹ̀, ki awa má ṣegbe?
10 Ọlọrun si ri iṣe wọn pe nwọn yipada
kuro li ọ̀na ibi wọn: Ọlọrun si ronupiwada
ibi ti on ti wi pe on o ṣe si wọn; on kò si
ṣe e mọ.

## ORI 4.

ṢUGBỌN o bà Jona ninu jẹ́ gidigidi, o si
binu pupọ̀.
2 O si gbadura si Oluwa, o si wipe, Emi
bẹ ọ, Oluwa, ọ̀rọ mi kọ yi nigbati mo wà
ni ilẹ mi? nitorina ni mo ṣe salọ si Tarṣiṣi
ni iṣaju: nitori emi mọ̀ pe, Ọlọrun olore-
ọfẹ ni iwọ, ati alãnu, o lọra lati binu, o si
ṣeun pupọ, o si ronupiwada ibi na.
3 Njẹ nitorina, Oluwa, emi bẹ ọ, gbà

Digitized by Google

ẹmi mi kuro lọwọ mi, nitori o sàn fun mi
lati kú jù ati wà lãyè.
4 Nigbana ni Oluwa wipe, Iwọ ha ṣe
rere lati binu?
5 Jona si jade kuro ni ilu na, o si joko
niha ila-õrun ilu ná, o si pa agọ kan nibẹ
fun ara rẹ̀, o si joko ni iboji labẹ rẹ̀, titi
yio fi ri ohun ti yio ṣẹ̀ ilu na.
6 Oluwa Ọlọrun si pese itakùn kan, o si
ṣe e ki o goke wá sori Jona; ki o le ṣiji bò
o lori; lati gbà a kuro ninu ibinujẹ rẹ̀.
Jona si yọ ayọ̀ nla nitori itakùn na.
7 Ṣugbọn Ọlọrun pese kokorò kan ni-
gbati ilẹ mọ́ ni ijọ keji, o si jẹ itakùn na, o
si rọ.
8 O si ṣe, nigbati õrun là, Ọlọrun si pese
ẹfufu gbigbona ti ila-õrùn; õrùn si pa Jona
lori, tobẹ̃ ti o rẹ̀ ẹ, o si fẹ́ ninu ara rẹ̀ lati
kú, o si wipe, O sàn fun mi lati kú jù ati
wà lãyè lọ.
9 Ọlọrun si wi fun Jona pe, O ha tọ́ fun
ọ lati binu nitori itakùn na? on si wipe, O
tọ́ fun mi lati binu titi de ikú.
10 Nigbana ni Oluwa wipe, Iwọ kẹdùn
itakùn na nitori eyiti iwọ kò ṣiṣẹ, bẹ̃li iwọ
kò mu u dagbà; ti o hù jade li oru kan ti
o si kú li oru kan.
11 Ki emi ki o má si da Ninefe si, ilu
nla nì, ninu eyiti jù ọkẹ-mẹfa ẹnia wà ti kò
le mọ̀ ọtun mọ̀ osì ninu ọwọ́ wọn, ati ọ̀pọ-
lọpọ ohun-ọsìn?

# MIKA.

## ORI 1.

ỌRỌ Oluwa ti o tọ̀ Mika ara Moraṣti wá li
ọjọ Jotamu, Ahasi, ati Hesekiah,
awọn ọba Juda, ti o ri niti Samaria ati
Jerusalemu.
2 Ẹ gbọ́, gbogbo ẹnyin enia; fetisilẹ,
Iwọ ilẹ aiye, ati ẹkún rẹ̀: si jẹ ki Oluwa
Ọlọrun ṣe ẹlẹri si nyin, Oluwa lati inu
tempili mimọ́ rẹ̀ wá.
3 Nitori, wo o, Oluwa jade lati ipò rẹ̀
wá, yio si sọ̀kalẹ, yio si tẹ̀ awọn ibi giga
aiye mọlẹ.
4 Awọn oke nla yio si yọ́ labẹ rẹ̀, awọn
afonifojì yio si pinyà, bi ida niwaju iná, bi
omi ti igbálọ ni ibi gẹ̀rẹgẹ̀rẹ.
5 Nitori irekọja Jakobu ni gbogbo eyi,
ati nitori ẹ̀ṣẹ ile Israeli. Kini irekọja Jako-
bu? Samaria ha kọ? ki si ni awọn ibi
giga Juda? Jerusalemu ha kọ?
6 Nitorina li emi o ṣe Samaria bi òkiti
pápa, ati bi gbigbin àjara: emi o si gbá
awọn okuta rẹ̀ danù sinu afonifojì, emi o si
ṣi awọn ipalẹ rẹ̀ silẹ.
7 Gbogbo awọn ere fifin rẹ̀ ni a o run
wom-wom, gbogbo awọn ẹbùn rẹ̀ li a o fi
iná sun, gbogbo awọn oriṣà rẹ̀ li emi o sọ
di ahoro: nitoriti o ko o jọ lati inu ẹbùn
panṣaga wá, nwọn o si pada si ẹ̀bùn pan-
ṣaga.
8 Nitori eyi li emi o ṣe pohunrere, ti
emi o si ma hu, emi o ma lọ ni ẹsẹ̀ lasan,
ati ni ihòho: emi o pohunrere bi dragoni,
emi o si ma kedaro bi awọn ọmọ ògongo.
9 Nitori ti ọgbẹ́ rẹ̀ jẹ alailewòtan; nito-
riti o wá si Juda; on de ẹnu-bode awọn
enia mi, ani si Jerusalemu.
10 Ẹ máṣe sọ ni Gati, ẹ máṣe sọkun rara:
ni ile Afra mo yi ara mi ninu ekuru.
11 Ẹ kọja lọ, iwọ ará Safiri pẹlu itiju
rẹ ni ihòhò: ara Saanani kò jade wá; ọ̀fọ̀
Beteseli yio gba iduro rẹ̀ lọwọ nyin.
12 Nitori ara Maroti nreti ire, ṣugbọn
ibi sọkalẹ ti ọdọ Oluwa wá si ẹnu bode
Jerusalemu.
13 Iwọ ara Lakiṣi, di kẹkẹ mọ ẹranko ti
o yara: on ni ibẹrẹ ẹ̀ṣẹ si ọmọbirin Sioni:
nitori a ri irekọja Israeli ninu rẹ.
14 Nitorina ni iwọ o ṣe fi iwe ikọ̀silẹ fun
Moreṣetigati: awọn ile Aksibi yio jẹ eke
si awọn ọba Israeli.
15 Sibẹ̀ emi o mu arole kan fun ọ wá,
Iwọ ara Mareṣa; ogo Israeli yio wá si
Adullamu.
16 Sọ ara rẹ di apari, si rẹ́ irun rẹ nitori
awọn ọmọ rẹ ẹlẹgẹ́; sọ apári rẹ di gbòro bi
idì; nitori a di wọn ni igbèkun lọ kuro
lọdọ rẹ.

Digitized by Google

## ORI 2.

EGBE ni fun awọn ti ngbìmọ aiṣedede, ti
nṣiṣẹ ibi lori akete wọn! nigbati oju-
mọ́ mọ́ nwọn nṣe e, nitoripe o wà ni agbara
ọwọ́ wọn.
2 Nwọn si nṣe ojukòkoro oko, nwọn si
nfi ipá gbà a: ati ile, nwọn a si mu wọn
lọ: nwọn si ni enia lara ati ile rẹ̀, ani enia
ati ini rẹ̀.
3 Nitorina bayi ni Oluwa wi; Kiyesi i,
emi ngbimọ̀ ibi si idile yi, ninu eyiti ọrùn
nyin kì yio le yọ; bẹni ẹnyin kì yio fi
igberaga lọ: nitori akokò ibi ni yi.
4 Li ọjọ na ni ẹnikan yio pa owe kan si
nyin, yio si pohunrere-ẹkun kikorò pe, Ni
kikò a kó wa tan? on ti pin ini enia mi:
bawo ni o ti ṣe mu u kuro lọdọ mi! o ti
pin oko wa fun awọn ti o yapa.
5 Nitorina iwọ kì yio ni ẹnikan ti yio ta
okùn nipa ìbo ninu ijọ enia Oluwa.
6 Nwọn ni, ẹ máṣe sọtẹlẹ, nwọn o sọtẹlẹ,
bi nwọn kò ba sọtẹlẹ bayi, itiju kì yio
kuro.
7 Iwọ ẹniti a npè ni ile Jakobu, Ẹmi
Oluwa ha bùku bi? iṣe rẹ̀ ha ni wonyi?
ọ̀rọ mi kò ha nṣe rere fun ẹni ti nrin dẽde
bi?
8 Ati nijelo awọn enia mi dide bi ọta
si mi: ẹnyin ti bọ́ ẹ̀wu ati aṣọ ibora kuro
lọdọ awọn ti nkọja li ailewu, bi awọn
ẹniti o kọ̀ ogun silẹ.
9 Obirin awọn enia mi li ẹnyin ti le
jade kuro ninu ile wọn daradara; ẹnyin
ti gbà ogo mi kuro lọwọ awọn ọmọ wọn
lailai.
10 Ẹ dide, ki ẹ si ma lọ; nitoripe eyi
kì iṣe ibi isimi: nitoriti o jẹ alaimọ́, yio
pa nyin run, ani iparun kikorò?
11 Bi enia kan ti nrin ninu ẹmi ati
itanjẹ ba ṣeke, wipe, emi o sọ asọtẹlẹ́ ti
ọti-waini ati ọti-lile fun ọ; on ni o tilẹ ṣe
woli awọn enia yi.
12 Ni kikó emi o kó nyin jọ, iwọ
Jakobu, gbogbo nyin; ni gbigbá emi o
gbá iyokù Israeli jọ; emi o si tò wọn jọ
pọ̀ gẹgẹ bi agutun Bosra, gẹgẹ bi ọwọ́
ẹran ninu agbo wọn: nwọn o si pariwo
nla nitori ọ̀pọlọpọ enia.
13 Ẹniti nfọni ti dide niwaju wọn:
nwọn ti fọ́, nwọn kọja lãrin bode, nwọn
si ti jade lọ nipa rẹ̀: ọba wọn o si kọja
lọ niwaju wọn, Oluwa ni yio si ṣe olori wọn.

## ORI 3.

EMI si wipe, Gbọ́, emi bẹ̀ nyin, ẹnyin
olori ni Jakobu, ati ẹnyin alakoso ile
Israeli; ti nyin kì iṣe lati mọ̀ idajọ bi?
2 Ẹnyin ti o korira ire, ti ẹ si fẹ ibi;
ti ẹ já awọ-ara wọn kuro lara wọn, ati
ẹran-ara wọn kuro li egungun wọn;
3 Awọn ẹniti o si jẹ ẹran-ara awọn enia
mi pẹlu, ti nwọn si họ́ awọ-ara wọn kuro
lara wọn, nwọn si fọ́ egungun wọn, nwọn
si ke wọn wẹwẹ, bi ti ikòko, ati gẹgẹ bi
ẹran ninu òdu.
4 Nigbana ni nwọn o kigbe pe Oluwa,
ṣugbọn on kì yio gbọ́ ti wọn: on o tilẹ
pa oju rẹ̀ mọ̀ kuro lọdọ wọn li akoko na,
gẹgẹ bi nwọn ti huwà alaifi ri ninu gbogbo
iṣe wọn.
5 Bayi ni Oluwa wi niti awọn woli ti
nṣì awọn enia mi li ọ̀na, ti nfi ehín wọn
bù ni ṣán, ti o si nkigbe wipe, Alafia; on
ẹniti kò fi nkan si wọn li ẹnu, awọn na si
mura ogun si i.
6 Nitorina oru yio ru nyin, ti ẹnyin kì
yio fi ri iran; òkunkun yio si kùn fun
nyin, ti ẹnyin kì o fi le sọtẹlẹ; õ̀rùn yio
si wọ̀ lori awọn woli, ọjọ yio si ṣokùnkun
lori wọn.
7 Oju yio si tì awọn ariran, awọn alasọ-
tẹlẹ̀ na yio si dãmu: nitõtọ, gbogbo wọn
o bò ete wọn: nitori idahùn kò si lati ọdọ
Ọlọrun.
8 Ṣugbọn nitõtọ emi kún fun agbara
nipa ẹmi Oluwa, ati fun idajọ, ati fun ipá,
lati sọ irekọja Jakobu fun u, ati lati sọ
ẹ̀ṣẹ Israeli fun u.
9 Gbọ́ eyi, emi bẹ̀ nyin, ẹnyin olori ile
Jakobu; ati awọn alakoso ile Israeli, ti o
korira idajọ, ti o si yi otitọ pada.
10 Ti o fi ẹjẹ kọ́ Sioni, ati Jerusalemu
pẹlu iwà ẹ̀ṣẹ.
11 Awọn olori rẹ̀ nṣe idajọ nitori ère,
awọn alufa rẹ̀ nkọ́ni fun ọyà, awọn woli
rẹ̀ si nsọtẹlẹ fun owo: sibẹ ni nwọn o
gbẹkẹle Oluwa, wipe, Oluwa kò ha wà
lãrin wa? ibi kan kì yio ba wa.
12 Nitorina nitori nyin ni a o ṣe ro
Sioni bi oko, Jerusalemu yio si di okìti,
ati oke-nla ile bi ibi giga igbo.

## ORI 4.

YIO si ṣe li ọjọ ikẹhin, a o fi oke ile
Oluwa kalẹ lori awọn oke-nla, a o si
gbe e ga jù awọn oke kekeke lọ; awọn
enia yio si ma wọ́ sinu rẹ̀.
2 Ọpọlọpọ orilẹ-ède yio si wá, nwọn o si

Digitized by Google

wipe, Ẹ wá, ẹ jẹ ki a goke lọ si oke-nlà
Oluwa, ati si ile Ọlọrun Jakobu; on o si
kọ́ wa li ọ̀na rẹ̀, awa o si ma rìn ni ipa-ọ̀na
rẹ̀: nitori lati Sioni ni ofin yio ti jade lọ,
ati ọ̀rọ Oluwa lati Jerusalemu.
3 On o si ṣe idajọ lãrin ọ̀pọlọpọ enia,
yio si bá alagbara orilẹ-ède rére wi; nwọn
o si fi idà wọn rọ ọbẹ-plau, ati ọ̀kọ wọn rọ
dojé: orilẹ-ède kì yio gbe idà soke si
orilẹ-ède, bẽni nwọn kì yio kọ́ ogun jijà
mọ.
4 Ṣugbọn nwọn o joko olukuluku labẹ
ajara rẹ̀ ati labẹ igi ọpọtọ rẹ̀; ẹnikan kì
yio si daiyà fò wọn: nitori ẹnu Oluwa
awọn ọmọ-ogun li o ti sọ ọ.
5 Nitori gbogbo awọn enia ni yio ma
rìn olukuluku li orukọ ọlọrun tirẹ̀, awa
o si ma rìn li orukọ Oluwa Ọlọrun wa lai
ati lailai.
6 Li ọjọ na, ni Oluwa wi, li emi o kó
amukun, emi o si ṣà ẹniti a le jade, ati
ẹniti emi ti pọn loju jọ;
7 Emi o si dá awọn amukun si fun
iyokù, emi o si sọ ẹniti a ta nù rére di
orilẹ-ède alagbara: Oluwa yio si jọba lori
wọn li oke-nla Sioni lati isisiyi lọ, ati si i
lailai.
8 Ati iwọ, Ile iṣọ agbo agùtan, odi
ọmọbirin Sioni, si ọdọ rẹ ni yio wá, ani
ijọba iṣãju; ijọba yio si wá si ọdọ ọmọbirin
Jerusalemu.
9 Njẹ kini iwọ ha nkigbe soke si? ọba
kò ha si ninu rẹ? awọn ìgbimọ rẹ ṣegbé
bi? nitori irora ti dì ọ mu bi obirin ti
nrọbi.
10 Ma rọbi, si bi, ọmọbirin Sioni, bi
ẹniti nrọbi: nitori nisisiyi ni iwọ o jade
lọ kuro ninu ilu, iwọ o si ma gbe inu
igbẹ́, iwọ o si lọ si Babiloni; nibẹ̀ ni a
o gbà ọ; nibẹ̀ ni Oluwa yio rà ọ padà
kuro lọwọ awọn ọta rẹ.
11 Ati nisisiyi ọ̀pọlọpọ orile-ède gbá jọ
si ọ, ti nwi pe, jẹ ki a sọ ọ di aimọ́, si jẹ
ki oju wa ki o wo Sioni.
12 Ṣugbọn nwọn kò mọ̀ erò Oluwa, bẽni
oye ìmọ rẹ̀ kò ye wọn: nitori on o kó wọn
jọ bi ití sinu ipaka.
13 Dide, si ma pakà, Iwọ ọmọbirin
Sioni: nitori emi o sọ iwo rẹ di irin, emi
o si sọ patakò rẹ di idẹ, iwọ o si run
ọ̀pọlọpọ enia womwom: emi o si yá ère
wọn sọtọ̀ fun Oluwa, ati inì wọn si Oluwa
gbogbo aiye.

ORI 5.

NISISIYI gbá ara rẹ jọ li ọwọ́, Iwọ
ọmọbirin ọwọ́: o ti dó tì wa; nwọn
o fi ọ̀pa lu onidajọ Israeli li ẹ̀rẹkẹ.
2 Ati iwọ Betlehemu Efrata; bi iwọ
ti jẹ kekere lãrin awọn ẹgbẹgbẹ̀run Juda,
ninu rẹ ni ẹniti yio jẹ olori ni Israeli yio
ti jade tọ̀ mi wá; ijade lọ rẹ̀ si jẹ lati
igbãni, lati ayieraiye.
3 Nitorina ni yio ṣe jọwọ wọn lọwọ,
titi di akokò ti ẹniti nrọbi yio fi bi:
iyokù awọn arakọnrin rẹ̀ yio si pada wá
sọdọ awọn ọmọ Israeli.
4 On o si duro yio si ma jẹ̀ li agbara
Oluwa, ni ọlanla orukọ Oluwa Ọlọrun rẹ̀;
nwọn o si wà, nitori nisisiyi ni on o tobi
titi de opin aiye.
5 Eleyi ni yio jẹ alafia, nigbati ara
Assiria yio wá si ilẹ wa; nigbati yio si
tẹ̀ awọn ãfin wa mọlẹ, nigbana li awa o
gbe oluṣọ agutan meje dide si i, ati olori
enia mẹjọ.
6 Nwọn o si fi idà pa ilẹ Assiria run,
ati ilẹ Nimrodu ni àbawọ̀ inu rẹ̀: yio si
gbà wa lọwọ ara Assiria nigbati o ba wá
ilẹ wa, ati nigbati o ba si ntẹ̀ àgbegbe
wa mọle.
7 Iyokù Jakobu yio si wà lãrin ọ̀pọ
enia bi irì lati ọdọ Oluwa wá, bi ọwarà
òjo lori koriko, ti kì idara duro de enia,
ti kì isi duro de awọn ọmọ enia.
8 Iyokù Jakobu yio si wà lãrin awọn
Keferi, lãrin ọ̀pọ enia bi kiniun, lãrin
awọn ẹranko igbo, bi ọmọkiniun lãrin
agbo agutan; eyiti, bi o ba là a ja, ti
itẹ̀ mọlẹ, ti isi ifaya pẹrẹpẹrẹ, kò si ẹniti
yio gbalà.
9 A o gbe ọwọ́ rẹ soke sori awọn ọ̀ta rẹ,
gbogbo awọn ọ̀ta rẹ, li a o si ke kuro.
10 Yio si ṣe li ọjọ na, ni Oluwa wi, ti
emi o ke awọn ẹṣin rẹ kuro lãrin rẹ, emi
o si pa awọn kẹkẹ́ ogun rẹ run.
11 Emi o si ke ilu-nla ilẹ rẹ kuro, emi
o si tì gbogbo odi rẹ ṣubu:
12 Emi o si ke iwà-ajẹ kuro lọwọ rẹ:
iwọ kì yio si ni alafọ̀ṣẹ mọ:
13 Ere fifin rẹ pẹlu li emi o ke kuro,
awọn ere rẹ kuro lãrin rẹ; iwọ kì o si ma
sin iṣẹ ọwọ́ rẹ mọ.
14 Emi o si tú igbo òriṣa rẹ kuro lãrin
rẹ: emi o si pa awọn ilu rẹ run.
15 Emi o si gbẹsan ni ibinu ati irunu
lara awọn keferi, ti nwọn kò ti igbọ́ ri.



Digitized by Google

## ORI 6.

EGBỌ́ nisisiyi ohun ti Oluwa wi; Dide,
ba oke nla wijọ, si jẹ ki oke kékèké
gbohùn rẹ.
2 Ẹ gbọ́ ẹjọ Oluwa, ẹnyin oke-nla, ati
ẹnyin ipilẹ ilẹ̀ aiye: nitori Oluwa mba
awọn enia rẹ̀ wijọ, yio si ba Israeli rojọ.
3 Enia mi, kini mo fi ṣe ọ? ati ninu
kini mo fi da ọ li agara? dahùn si i.
4 Nitori mo ti mu ọ goke lati ilẹ
Egipti wá, mo si rà ọ padà lati ile ẹrú
wá; mo si rán Mose, Aaroni, ati Miriamu
siwaju rẹ.
5 Enia mi, ranti nisisiyi ohun ti Balaki
ọba Moabu gbèro, ohun ti Balaamu ọmọ
Beori dá a lohùn lati Ṣittimu titi de
Gilgali; ki ẹ ba le mọ̀ ododo Oluwa.
6 Kini emi o ha mu wá siwaju Oluwa, ti
emi o fi tẹ̀ ara mi ba niwaju Ọlọrun giga?
ki emi ha wá siwaju rẹ̀ pẹlu ọrẹ-ẹbọ sisun,
pẹlu ọmọ malu ọlọdún kan?
7 Inu Oluwa yio ha dùn si ẹgbẹgbẹ̀run
àgbo, tabi si ẹgbẹgbãrun iṣàn òroro? emi o
ha fi àkọbi mi fun irekọja mi, iru-ọmọ inu
mi fun ẹ̀ṣẹ ọkàn mi?
8 A ti fi hàn ọ, Iwọ enia, ohun ti o dara;
ati ohun ti Oluwa bère lọwọ rẹ, bikoṣe ki o
ṣe otitọ, ki o si fẹ ãnu, ati ki o rìn ni irẹ̀lẹ
pẹlu Ọlọrun rẹ?
9 Ohùn Oluwa kigbe si ilu na, ọlọgbọ́n
yio si ri orukọ rẹ; ẹ gbọ́ ọ̀pa na, ati ẹniti o
yàn a?
10 Iṣura ìwa buburu ha wà ni ile enia
buburu sibẹ̀, ati òṣuwọ̀n aikún ti o jẹ ohun
ibinú?
11 Ki emi ha kà wọn si mimọ́ pẹlu òṣu-
wọ̀n buburu, ati pẹlu àpo òṣuwọ̀n ẹ̀tan?
12 Ti awọn ọlọrọ̀ rẹ̀ kún fun ìwa-ipá,
ati awọn ti ngbe inu rẹ̀ ti sọrọ eké, ahọn
wọn si kún fun ẹ̀tan li ẹnu wọn.
13 Nitorina pẹlu li emi o ṣe mu ọ ṣàisan
ni lilù ọ, ni sisọ ọ dahoro nitori ẹ̀ṣẹ rẹ.
14 Iwọ o jẹun, ṣugbọn iwọ kì yio yo;
idábẹ yio wà lãrin rẹ; iwọ o kó kuro,
ṣugbọn iwọ kì o lọ lailewu; ati eyi ti o kó
lọ li emi o fi fun idà.
15 Iwọ o gbìn, ṣugbọn iwọ kì yio ká;
iwọ o tẹ̀ igi olifi, ṣugbọn iwọ kì o fi ororo
kunra; ati eso àjara, ṣugbọn iwọ kì o mu
ọti-waini.
16 Nitori ti a pa aṣẹ Omri mọ́, ati gbo-
gbo iṣẹ ile Ahabu, ẹ si rìn ni ìmọ wọn; ki
emi ba le sọ ọ di ahoro, ati awọn ti ngbe
inu rẹ di ẹ̀gan: ẹnyin o si rù ẹgan enia
mi.

## ORI 7.

EGBE ni fun mi! nitori emi dàbi ikojọpọ̀
eso ẽrùn, bi ẽṣẹ́ ikorè eso àjara: kò si
ití kan lati jẹ: akọso ti ọkàn mi fẹ.
2 Oninurere ti run kuro li aiye: kò si si
olotitọ kan ninu enia: gbogbo wọn ba fun
ẹ̀jẹ, olukuluku wọn nfi àwọn dẹ arakọnrin
rẹ̀.
3 Ọwọ́ wọn ti mura tan lati ṣe buburu,
olori mbère, onidajọ si mbère fun ẹsan;
ẹni-nla nsọ ìro ika rẹ̀, nwọn si nyi i po.
4 Ẹniti o sànjulọ ninu wọn dàbi ẹ̀gun:
ìduroṣiṣin julọ mú jù ẹgún ọgbà lọ: ọjọ
awọn olùṣọ rẹ ati ti ìbẹwo rẹ de; nisisiyi
ni idãmu wọn o de.
5 Ẹ má gba ọrẹ́ kan gbọ́, ẹ má si gbẹkẹ̀le
amọ̀na kan: pa ilẹkùn ẹnu rẹ mọ fun ẹniti
o sùn ni õkan-àiya rẹ.
6 Nitori ọmọkọnrin nṣàibọ̀wọ fun baba,
ọmọbirin dide si ìya rẹ̀, aya-ọmọ si iyakọ
rẹ̀; ọta olukuluku ni awọn ara ile rẹ̀.
7 Nitorina emi o ni ireti si Oluwa: emi
o duro de Ọlọrun igbala mi: Ọlọrun mi yio
gbọ́ temi.
8 Má yọ̀ mi, Iwọ ọta mi: nigbati mo ba
ṣubu, emi o dide; nigbati mo ba joko li
okùnkun, Oluwa yio jẹ imọlẹ fun mi.
9 Emi o rù ibinu Oluwa, nitori emi ti
dẹṣẹ si i, titi yio fi gbà ẹjọ mi rò, ti yio si
ṣe idajọ mi; yio mu mi wá si imọlẹ, emi o
si ri ododo rẹ̀.
10 Nitori ọta mi yio ri i, itiju yio si bò
ẹniti o wipe, Nibo ni Oluwa Ọlọrun rẹ wà?
oju mi yio ri i, nisisiyi ni yio di itẹ̀mọlẹ bi
ẹrẹ̀ ita.
11 Ọjọ ti a o mọ odi rẹ, ọjọ na ni aṣẹ
yio jinà rére.
12 Ọjọ na ni nwọn o si ti Assiria wá
sọdọ rẹ, ati lati ilu olodi, ati lati ilẹ iṣọ́
alagbara titi de odo, ati lati okun de okun,
ati oke-nla de oke-nla.
13 Ilẹ na yio si di ahoro fun awọn ti
ngbe inu rẹ̀, nitori ẹso ìwa wọn.
14 Fi ọpa rẹ bọ́ enia agbo ini rẹ, ti ndá-
gbe inu igbó lãrin Karmeli: jẹ ki wọn jẹ̀
ni Baṣani ati Gileadi, bi ọjọ igbãni.
15 Bi ọjọ ti o jade kuro ni ilẹ Egipti li
emi o fi ohun iyanu han a.
16 Awọn orilẹ-ède yio ri, oju o si tì wọn
ninu gbogbo agbara wọn: nwọn o fi ọwọ́ le
ẹnu, eti wọn o si di.
17 Nwọn o lá erùpẹ bi ejò, nwọn o si
jade kuro ninu ihò wọn bi ekòlo ilẹ: nwọn
o bẹ̀ru Oluwa Ọlọrun wa, nwọn o si bẹ̀ru
nitori rẹ.

Digitized by Google

18 Tani Ọlọrun bi iwọ, ti o ndari aiṣe-
dede jì, ti o nre iyokù ini rẹ̀ kọja? kò dá
ibinu rẹ̀ duro titi lai, nitori on ni inudidun
si ãnu.
19 Yio yipadà, yio ni iyọnú si wa; yio
si tẹ̀ aiṣedede wa ba; iwọ o si sọ gbogbo
ẹ̀sẹ wọn sinu ọgbun okun.
20 Iwọ o fi otitọ fun Jakobu, ãnu fun
Abrahamu, ti iwọ ti bura fun awọn baba
wa, lati ọjọ igbani.

# NAHUMU.

## ORI 1.

ỌRỌ-ÌMỌ̀ niti Ninefe. Iwe iran Nahu-
mu ara Elkoṣi.
2 Ọlọrun njowu, Oluwa si ngbẹsan;
Oluwa ngbẹsan, o si kún fun ibinu; Oluwa
ngbẹsan li ara awọn ọta rẹ̀, o si fi ibinu dè
awọn ọta rẹ̀.
3 Oluwa lọra lati binu, o si tobi li
agbara, ni didasilẹ̀ kì yio da enia buburu
silẹ: Oluwa ni ọ̀na rẹ̀ ninu ãjà ati ninu ìji,
awọsanma si ni ekuru ẹsẹ̀ rẹ̀.
4 O ba okun wi, o si mu ki o gbẹ, o si
sọ gbogbo odò di gbigbẹ: Baṣani di alai-
lera, ati Karmeli, itànna Lebanoni si rọ.
5 Awọn oke-nla mì nitori rẹ̀, ati awọn
oke kékèké di yiyọ́, ilẹ aiye si joná niwaju
rẹ̀, ani aiye ati gbogbo awọn ti ngbe inu
rẹ̀.
6 Tani o le duro niwaju ibinu rẹ̀? tani
o si le duro gba gbigboná ibinu rẹ̀? a dà
ibinu rẹ̀ jade bi iná, on li o si fọ́ awọn
apata.
7 Rere li Oluwa, ãbo li ọjọ ipọnju; on
si mọ̀ awọn ti o gbẹkẹle e.
8 Ṣugbọn ikún omi akunrekọja li on fi
ṣe iparun ibẹ̀ na de opin, okùnkun yio si
ma lepa awọn ọta rẹ̀.
9 Kili ẹnyin ngbirò si Oluwa? on o ṣe
iparun de opin, ipọnju kì yio dide lẹrinkeji.
10 Nitori sã ti a ba ká wọn jọ bi ẹ̀gun,
ati sã ti wọn iba mu amupara bi ọmùti,
a o run wọn gẹgẹ bi koriko ti o ti gbẹ de
opin.
11 Ẹnikan ti ọdọ rẹ jade wá, ti o ngbirò
ibi si Oluwa, olugbìmọ buburu.
12 Bayi ni Oluwa wi; bi nwọn tilẹ pé,
ti nwọn si pọ̀ niye, ṣugbọn bayi ni a o ke
nwọn lulẹ, nigbati on o ba kọja. Bi mo
tilẹ ti pọn ọ loju, emi kì yio pọn ọ loju
mọ.
13 Nitori nisisiyi li emi o fà ajàga rẹ̀
kuro li ọrun rẹ, emi o si dá idè rẹ wọnni li
agbedemeji.
14 Oluwa si ti fi aṣẹ kan lelẹ nitori rẹ
pe, ki a má ṣe gbìn ninu orukọ rẹ mọ: lati
inu ile ọlọrun rẹ wá li emi o ke ere fifin ati
ere didà kuro: emi o wà iboji rẹ; nitori
ẹgbin ni iwọ.
15 Wò o lori oke nla ẹsẹ̀ ẹniti o mu ihìn
rere wá, ẹniti o nkede alafia! Iwọ Juda,
pa aṣẹ rẹ ti o ni irònu mọ, san ẹ̀jẹ́ rẹ: ni-
tori enia buburu kì yio kọja lãrin rẹ mọ; a
ti ké e kuro patapata.

## ORI 2.

ATUNIKA de iwaju rẹ (Ninefe): pa ile-
iṣọ mọ, ṣọ ọ̀na na, di àmurè ẹ̀gbẹ rẹ
ko le, mura girigiri.
2 Nitori Oluwa tun pada si ọlanla Jako-
bu, gẹgẹ bi ọlanla Israeli: atunidanù ti
tú wọn danù, nwọn si ba ẹka àjara wọn
jẹ.
3 A sọ asà awọn ọkọnrin alagbara rẹ̀ di
pupa, awọn akin wọn wọ̀ odòdó: kẹkẹ́
ogun yio mã kọ bi iná li ọjọ ipèse rẹ̀, igi
firi li a o si mì titi.
4 Ariwo kẹkẹ́ ni igboro, nwọn o si ma
gbún ara wọn ni ọ̀na gbigbòro, nwọn o dabi
etùfu, nwọn o kọ́ bi mànamána.
5 On o ṣe aṣàro awọn ọlọla rẹ̀: nwọn o
kọsẹ̀ ni irìn wọn; nwọn o yara si ibi odi
rẹ̀, a o si pèse ãbo rẹ̀.
6 A o ṣi ilẹ̀kun odò wọnni silẹ, a o si sọ
ãfin na di yiyọ́.
7 Eyi ti a ti fi idi rẹ̀ mulẹ li a o si dì ni
igbèkun lọ, a o si mu u goke wá, ati awọn
iranṣẹbirin rẹ̀ yio fi ohùn bi ti oriri ṣe
amọ̀na rẹ̀, nwọn a ma lù aiya wọn.
8 Ṣugbọn Ninefe li ọjọ ti o ti wà bi
adagun omi: sibẹ̀ nwọn o salọ kuro. Duro,

Digitized by Google

duro! ni nwọn o ma ke; ṣugbọn ẹnikan
kì yio wò ẹhìn.
9 Ẹ ko ikogun fàdakà, ẹ ko ikogun
wurà! ati iṣura wọn ailopin na, ati ogo
kuro ninu gbogbo ohunelò ti a fẹ́.
10 On ti ṣòfo, o ti di asan, o si di ahoro:
aiyà si yọ́, ẽkún nlù ara wọn, irora pupọ̀ si
wà ninu gbogbo ẹgbẹ́, ati oju gbogbo wọn
si kó dudu jọ.
11 Nibo ni ibugbé awọn kiniun wà, ati
ibujẹ awọn ọmọ kiniun, nibiti kiniun, ani
agbà kiniun, ti nrìn, ati ọmọ kiniun, kò si
si ẹniti o dẹruba wọn?
12 Kiniun ti fàya pẹrẹpẹrẹ tẹrùn fun
awọn ọmọ rẹ̀, o si fun li ọrun pa fun awọn
abo kiniun rẹ̀, o si fi ohun ọdẹ kún isà rẹ̀,
ati ihò rẹ̀ fun onjẹ agbara.
13 Kiyesi i, emi dojukọ ọ, ni Oluwa
awọn ọmọ ogun wi, emi o si fi kẹkẹ́ rẹ̀
wọnni joná ninu ẽfin, idà yio si jẹ ọmọ
kiniun rẹ wọnni run: emi o si ke ohun ọdẹ
rẹ kuro lori ilẹ aiye, ohùn awọn ojiṣẹ rẹ li
a kì yio si tún gbọ́ mọ.

## ORI 3.

EGBE ni fun ilu ẹjẹ̀ nì! gbogbo rẹ̀ kun
fun eké, ati olè, ijẹ kò kuro;
2 Ariwo pàṣan, ati ariwo kikùn kẹkẹ́,
ati ti ijó awọn ẹṣin, ati ti fifò kẹkẹ́.
3 Ẹlẹṣin ti gbe idà rẹ̀ ti nkọ mànа, ati
ọkọ̀ rẹ̀ ti ndán yànran si oke: ọ̀pọlọpọ si li
awọn ẹniti a pa, ati ọ̀pọlọpọ okú; okú kò
si ni opin; nwọn nkọsẹ̀ li ara okú wọn
wọnni:
4 Nitori ọ̀pọlọpọ awọn panṣagà àgbere ti
o roju rere gbà, iya ajẹ ti o ntà awọn orilẹ-
ède nipasẹ̀ panṣaga rẹ̀, ati idile nipasẹ̀ ajẹ
rẹ̀.
5 Kiyesi i, emi dojukọ́ ọ, ni Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi; emi o si ká aṣọ itẹlẹ̀di rẹ̀ li
oju rẹ, emi o si fi ihòho rẹ hàn awọn orilẹ-
ède, ati itiju rẹ hàn awọn ilẹ̀ ọba.
6 Emi o da ẹgbin ti o ni irira si ọ lara,
emi o si sọ ọ di alaimọ́, emi o si gbe ọ kalẹ
bi ẹni ifiṣẹlẹyà.
7 Yio si ṣe pe, gbogbo awọn ti o wò ọ
yio sa fun ọ, nwọn o si wipe, A ti fi Ninefe
ṣòfo: tani yio kẹdùn rẹ̀? nibo ni emi o ti
wá olutùnu fun ọ?
8 Iwọ ha sàn jù No-ammoni, eyiti o wà
lãrin odò ti omi yika kiri, ti agbara rẹ̀ jẹ
okun, ti odi rẹ̀ si ti inu okun jade wá?
9 Etiopia ati Egipti li agbara rẹ̀, kò si li
opin; Puti ati Lubimu li awọn olùranlọwọ
rẹ.
10 Sibẹ̀sibẹ̀ a kó o lọ, o lọ si oko-ẹrú: awọn
ọmọ wẹ́wẹ rẹ̀ li a fi ṣánlẹ̀ pẹlu li ori ita
gbogbo; nwọn si di ibò nitori awọn ọlọla
rẹ̀ ọkọnrin, gbogbo awọn ọlọla rẹ̀ li a si fi
ẹwọ̀n dì.
11 Iwọ pẹlu o si yó ọti; a o si fi ọ pamọ,
iwọ pẹlu o si ma ṣe afẹri ãbò nitori ti ọta
na.
12 Gbogbo ile-iṣọ agbara rẹ yio dabi igi
ọpọ̀tọ pẹlu akọpọn ọpọ̀tọ: bi a ba gbọ̀n
wọn, nwọn o si bọ si ẹnu ọjẹun.
13 Kiye si i, obirin li awọn enia rẹ lãrin
rẹ: oju ibodè ilẹ rẹ li a o ṣi silẹ gbaguda
fun awọn ọta rẹ: iná yio jo ikere rẹ.
14 Iwọ pọn omi de ihamọ, mu ile iṣọ rẹ
le: wọ̀ inu amọ̀, ki o si tẹ̀ erupẹ̀, ki o si ṣe
ibiti a nsun okuta-amọ̀ ki o le.
15 Nibẹ̀ ni iná yio jo ọ run; idà yio ké
ọ kuro, yio si jẹ ọ bi kòkoro: sọ ara rẹ di
pupọ̀ bi kòkoro, si sọ ara rẹ di pupọ̀ bi ẽṣu.
16 Iwọ ti sọ awọn oniṣòwo rẹ di pupọ̀ jù
iràwọ oju ọrun lọ: kokòro nà ara rẹ̀, o si
fò lọ.
17 Awọn alade rẹ dabi eṣú, awọn ọgagun
rẹ si dabi ẹlẹngà nla, eyiti ndó sinu ọgbà
li ọjọ otutù, ṣugbọn nigbati õrùn là, nwọn
sa lọ, a kò si mọ̀ ibiti wọn gbe wà.
18 Awọn olùṣọ agùtan rẹ ntõgbe, Iwọ
ọba Assiria: awọn ọlọla rẹ yio ma gbe inu
ekuru: awọn enia rẹ si tuka lori oke-nla,
ẹnikan kò si kó wọn jọ.
19 Kò si ipajumọ fun ifarapa rẹ; ọgbẹ
rẹ kún fun irora, gbogbo ẹniti o gbọ́ ihin
rẹ yio pàtẹwọ le ọ lori, nitori li ori tani
ìwa-buburu rẹ kò ti kọja nigbagbogbo?

Digitized by Google

# HABAKKUKU.

## ORI 1.

ỌRỌ-ÌMỌ ti Habakkuku woli rí.

2 Oluwa, emi o ti ke pẹ to, ti iwọ kì yio fi gbọ́! ti emi o kigbe si ọ, niti ìwa-ipa, ti iwọ kì yio si gbalà!

3 Ẽṣe ti o mu mi ri aiṣedede, ti o si jẹ ki nma wò ìwa-ìka? nitori ikógun ati ìwa-ipá wà niwaju mi: awọn ti si nrú ijà ati ãwọ̀ soke mbẹ.

4 Nitorina li ofin ṣe di ẹ̀ro, ti idajọ kò si jade lọ li ẹtọ́; nitoriti ẹni buburu yi olododo ka; nitorina ni idajọ ẹbi ṣe njade.

5 Ẹ wò inu awọn keferi, ki ẹ si wò o, ki hà ki o si ṣe nyin gidigidi: nitoriti emi o ṣe iṣẹ kan li ọjọ nyin, ti ẹ kì yio si gbagbọ́, bi a tilẹ sọ fun nyin.

6 Nitoripe, wò o, emi gbe awọn ara Kaldea dide, orilẹ-ède ti o korò, ti o si wára, ti yio rìn ibú ilẹ na ja, lati ni ibùgbe wọnni, ti kì iṣe ti wọn.

7 Nwọn ni ẹ̀ru, nwọn si fò ni laiyà: idajọ wọn, ati ọlanla wọn, yio ma ti inu wọn jade.

8 Ẹṣin wọn pẹlu yara jù ẹkùn lọ, nwọn si muná jù ikõkò aṣãlẹ lọ: ẹlẹṣin wọn yio si tàn ara wọn ka, ẹlẹṣin wọn yio si ti ọ̀na jijìn réré wá; nwọn o si fò bí idì ti nwára lati jẹun.

9 Gbogbo wọn o si wá fun ìwa-ipá; iwò oju wọn o si wà siwaju, nwọn o si kó igbèkun jọ bi yanrìn.

10 Nwọn o si ma fi awọn ọba ṣẹsín, awọn ọmọ alade yio si di ẹni-ẹ̀gan fun wọn: gbogbo ibi agbara ni nwọn o si fi rẹrin; nitoripe nwọn o ko erupẹ̀ jọ, nwọn o si gbà a.

11 Nigbana ni inu rẹ̀ yio yipadà, yio si rekọja, yio si ṣẹ̀, ni kikà agbara rẹ̀ yi si iṣẹ òriṣa rẹ̀.

12 Lati aiyeraiye ki iwọ ti wà? Oluwa Ọlọrun mi, Ẹni-Mimọ́ mi? awa kì yio kú. Oluwa, iwọ ti yàn wọn fun idajọ; Ọlọrun alagbara, iwọ ti fi ẹsẹ̀ wọn mulẹ fun ibawi.

13 Oju rẹ mọ́ jù ẹniti iwò ibi lọ, iwọ kò si lè wò ìwa-ìka: nitori kini iwọ ha ṣe nwò awọn ti nhùwa arekerekè, ti o si pa ẹnu rẹ mọ, nigbati ẹni-buburu jẹ ẹniti iṣe olododo jù u run?

14 Ti iwọ si nṣe enia bi ẹja okun, bi ohun ti nrakò, ti kò ni alakoso lori wọn?

15 Iwọ ni àwọn lati fi gbé gbogbo wọn, nwọn nfi àwọn mu wọn, nwọn si nfi awò wọn kó wọn: nitorina ni nwọn ṣe nyọ̀, ti inu wọn si ndùn.

16 Nitorina, nwọn nrubọ si àwọn wọn, nwọn si nsùn turari fun awò wọn; nitori nipa wọn ni ipin wọn ṣe li ọrá, ti onjẹ wọn si fi di pupọ̀.

17 Nitorina, nwọn o ha ma dà àwọn wọn, nwọn kì yio ha dẹkun lati ma fọ́ orilẹ-ède gbogbo?

## ORI 2.

LORI ibuṣọ́ mi li emi o duro, emi o si gbe ara mi kà ori alore, emi o si ṣọ lati ri ohun ti yio sọ fun mi, ati èsi ti emi o fi, nigbati a ba mba mi wi.

2 Oluwa si da mi lohùn, o si wipe, Kọ iran na, ki o si hàn a lara wàlã, ki ẹniti nkà a, le ma sare.

3 Nitori iran na jẹ ti igbà kan ti a yàn, yio ma yára si igbẹ̀hin, kì yio si ṣeke, bi o tilẹ̀ pẹ, duro dè e, nitori ni dide, yio de, kì yio pẹ.

4 Kiyesi i, ọkàn rẹ̀ ti o gbega, kò duro ṣinṣin ninu rẹ̀; ṣugbọn olododo yio wà nipa ìgbagbọ́ rẹ̀.

5 Bẹ̃ni pẹlu, nitoriti ọti-waini li ẹtàn, agberaga enia li on, kì isi simi, ẹniti o sọ ifẹ rẹ̀ di gbigbõrò bi ipò-okú, o si dabi ikú, a kò si lè tẹ́ ẹ lọrun, ṣugbọn o kó gbogbo orilẹ-ède jọ si ọdọ, o si gbá gbogbo enia jọ si ọdọ rẹ̀:

6 Gbogbo awọn wọnyi kì yio ma pa owe si i, ti nwọn o si ma kọ orin owe si i, wipe, Egbe ni fun ẹniti nmu ohun tĩ kì iṣe tirẹ̀ pọ̀ si i! yio ti pẹ to? ati fun ẹniti ndi ẹrẹ̀ ilọnilọwọgbá ru ara rẹ̀.

7 Awọn ti o yọ ọ lẹnu, kì yio ha dide lojiji? awọn ti o wahalà rẹ kì yio ha ji? iwọ kì yio ha si di ikogun fun wọn?

8 Nitori iwọ ti kó orilẹ-ède pupọ̀, gbogbo iyokù awọn enia na ni yio kó ọ;

Digitized by Google

nitori ẹjẹ̀ enia, ati ìwa-ipá ilẹ na, ti ilu
na, ati ti gbogbo awọn ti ngbe inu rẹ̀.
9 Egbe ni fun ẹniti njẹ erè ijẹkujẹ si ile
rẹ̀, ki o lè ba gbe itẹ́ rẹ̀ ka ibi giga, ki a
lè ba gbà a silẹ kuro lọwọ ibi!
10 Iwọ ti gbìmọ itìju si ile rẹ, nipa
kike enia pupọ̀ kuro, o si ti ṣẹ̀ si ọkàn rẹ.
11 Nitoriti okuta yio kigbe lati inu
ogiri wá, ati igi-idábu lati inu òpo wá
yio si da a lohùn.
12 Egbe ni fun ẹniti o fi ẹjẹ̀ kọ ilu, ti o
si fi aiṣedede tẹ̀ ilu nla do.
13 Kiyesi i, ti Oluwa awọn ọmọ-ogun
kọ́, pe, ki awọn enia na ma ṣe lãla fun
iná, ati ki awọn enia na si ma ṣe ara wọn
li ãrẹ̀ fun asan?
14 Nitoriti aiye yio kún fun ìmọ ogo
Oluwa, bi omi ti bò okun.
15 Egbe ni fun ẹniti o fi ohun mimu
fun aladugbo rẹ̀, ti o si fi ọti-lile rẹ fun
u, ti o si jẹ ki o mu amupara pẹlu, ki iwọ
ba le wò ihòho wọn!
16 Itìju bò ọ nipò ogo, iwọ mu pẹlu,
ki abẹ́ rẹ le hàn, ago ọwọ́ ọtun Oluwa ni
a o yipadà si ọ, ati tutọ itìju lara ogo
rẹ.
17 Nitori ti ìwa-ipá ti Lebanoni yio
bò ọ, ati ikogun awọn ẹranko, ti o bà
wọn li ẹ̀ru, nitori ẹjẹ̀ enia, ati ìwa ipá
ilẹ na, ti ilu na, ati ti gbogbo awọn ti ngbe
inu rẹ̀.
18 Erè kini ere fínfin nì, ti oniṣọna
rẹ̀ fi gbẹ́ ẹ; ere didà, ati olúkọ eké, ti
ẹniti nṣe iṣẹ rẹ̀ fi gbẹkẹ̀le e, lati ma ṣe ere
ti o yadi?
19 Egbe ni fun ẹniti o wi fun igi pe,
Ji; fun okuta ti o yadi pe, Dide, on o kọ́
ni! Kiyesi i, wurà ati fadakà li a fi bò o
yika, kò si si ẽmi kan ninu rẹ̀.
20 Ṣugbọn Oluwa mbẹ ninu tempili
rẹ̀ mimọ́; jẹ ki gbogbo aiye pa rọ́rọ ni-
waju rẹ̀.

## ORI 3.

ADURA Habakkuku woli lara Sigi-
onoti.
2 Oluwa, mo ti gbọ́ ohùn rẹ, ẹ̀ru si
bà mi: Oluwa, mu iṣẹ rẹ sọji lãrin ọdun,
lãrin ọdun sọ wọn di mimọ̀; ni ibinu
ranti ãnu.
3 Ọlọrun yio ti Temani wá, ati Ẹni-
Mimọ́ lati oke Parani. Ogo rẹ̀ bò awọn
ọrun, ilẹ aiye si kun fun iyìn rẹ̀.
4 Didán rẹ̀ si dabi imọlẹ; itanṣan nti
iha rẹ̀ wá: nibẹ̀ si ni ipamọ agbara rẹ̀ wà.
5 Ajàkalẹ arùn nlọ niwaju rẹ̀, ati okun-
run njade lati ẹsẹ̀ rẹ̀ lọ.
6 O duro, o si wọ̀n ilẹ aiye: o wò, o
si mu awọn orilẹ-ède warìri; a si tú awọn
oke-nla aiyeraiye ká, awọn oke kékèké
aiyeraiye si tẹba: ọ̀na rẹ̀ aiyeraiye ni.
7 Mo ri agọ Kuṣani labẹ ipọnju: awọn
aṣọ-ikele ilẹ̀ Midiani si warìri.
8 Oluwa ha binu si awọn odò? ibinu
rẹ̀ ha wà si awọn odò? ibinu rẹ̀ ha wà
si okun, ti iwọ fi ngùn ẹṣin rẹ ati kẹkẹ́
igbàla rẹ?
9 A ṣi ọrun rẹ̀ silẹ patapata, gẹgẹ bi
ibura awọn ẹ̀ya, ani ọ̀rọ rẹ. Iwọ ti fi
odò là ilẹ aiye.
10 Awọn oke-nla ri ọ, nwọn si warìri:
akúnya omi kọja lọ: ibú fọ̀ ohùn rẹ̀, o
si gbe ọwọ́ rẹ̀ si oke.
11 Òrùn ati oṣupa duro jẹ ni ibùgbe
wọn: ni imọlẹ ọfà rẹ ni nwọn lọ, ati ni
didán ọ̀kọ rẹ ti nkọ màna.
12 Ni irúnu ni iwọ rìn ilẹ na ja, ni
ibinu ni iwọ ti tẹ̀ awon orilẹ-ède rẹ́.
13 Iwọ jade lọ fun igbàla awọn enia
rẹ, fun igbàla ẹni atororosi rẹ; iwọ ti ṣá
awọn olori kuro ninu ile awọn enia bu-
buru, ni fifi ipinlẹ hàn titi de ọrùn.
14 Iwọ ti fi ọ̀pa rẹ̀ lu awọn olori iletó
rẹ̀ já: nwọn rọ́ jade bi ãjà lati tu mi ka:
ayọ̀ wọn ni bi ati jẹ talakà run nikọ̀kọ.
15 Iwọ fi awọn ẹṣin rẹ rìn okun ja,
okìti omi nla.
16 Nigbati mo gbọ́, ikùn mi warìri;
etè mi gbọ̀n li ohùn na; ibàjẹ wọ̀ inu
egungun mi lọ, mo si warìri ni inu mi,
ki emi ba le simi li ọjọ ipọnju: nigbati o
ba goke tọ̀ awọn enia lọ, yio ke wọn kuro.
17 Bi igi ọpọ̀tọ kì yio tilẹ tanná, ti
eso kò si ninu àjara; iṣẹ igi-olifi yio jẹ
aṣedanù, awọn oko kì yio si mu onjẹ
wá; a o ke agbo-ẹran kuro ninu agbo, ọwọ́
ẹran kì yio si si ni ibùso mọ:
18 Ṣugbọn emi o ma yọ̀ ninu Oluwa,
emi o ma yọ̀ ninu Ọlọrun igbàla mi.
19 Oluwa Ọlọrun ni agbara mi, on o si
ṣe ẹsẹ̀ mi bi ẹsẹ̀ agbọ̀nrin, lori ibi giga mi
ni yio si mu mi rìn. Si olori akọrin lara
ohun-ọnà orin olokùn mi.

Digitized by Google

# SEFANIAH.

## ORI 1.

ỌRỌ Oluwa ti o tọ̀ Sefaniah wá ọmọ
Kuṣi, ọmọ Gedaliah, ọmọ Amariah,
ọmọ Hisikiah, li ọjọ Josiah, ọmọ Amoni
ọba Juda.
2 Oluwa wipe, emi o mu gbogbo nkan
kuro lori ilẹ na patapata.
3 Emi o mu enia ati ẹranko kuro;
emi o mu ẹiyẹ oju ọrun kuro, ati ẹja inu
okun, ati ohun idigbòlu pẹlu awọn enia
buburu; emi o si ké enia kuro lori ilẹ, ni
Oluwa wi.
4 Emi o nà ọwọ́ mi pẹlu sori Juda, ati
sori gbogbo ara Jerusalemu; emi o si ké
iyokù Baali kuro nihinyi, ati orukọ Ke-
marimu pẹlu awọn alufa;
5 Ati awọn ti nsìn ogun ọrun lori
orule: awọn ti nsìn, ti nfi Oluwa bura,
ti si nfi Malkomu bura;
6 Ati awọn ẹniti o yipadà kuro lọdọ
Oluwa; ati awọn ẹniti kò ti wá Oluwa,
bẹ̃ni nwọn kò si bère rẹ̀.
7 Pa ẹnu rẹ mọ niwaju Oluwa Ọlọrun:
nitoriti ọjọ Oluwa kù si dẹ̀dẹ: nitori
Oluwa ti pesè ẹbọ kan silẹ̀, o si ti yà awọn
alapèjẹ rẹ̀ si mimọ́.
8 Yio si ṣe li ọjọ ẹbọ Oluwa, ti emi o
bẹ̀ awọn olori wò, ati awọn ọmọ ọba, ati
gbogbo ilu awọn ti o wọ̀ ajẹ̀ji aṣọ.
9 Li ọjọ na gan li emi o bẹ̀ gbogbo
awọn ti nfò le iloro wò pẹlu, ti nfi ìwa-ipá
on ẹ̀tan kún ile oluwa wọn.
10 Yio si ṣe li ọjọ na, li Oluwa wi,
ohùn ẹkún yio ti ihà bodè-ẹja wá, ati hihu
lati ihà keji wá, ati iro nla lati oke-
kékèké wọnni wá.
11 Hu, ẹnyin ara Maktẹsi, nitoripe
gbogbo enia onișòwo li a ti ke lu ilẹ; gbo-
gbo awọn ẹniti o nrù fàdakà li a ke kuro.
12 Yio si ṣe li akokò na, li emi o fi
fitilà wá Jerusalemu kiri, emi o si bẹ̀
awọn enia ti o silẹ sinu gẹ̀dẹgẹdẹ̀ wọn wò:
awọn ti nwi li ọkàn wọn pe, Oluwa kì yio
ṣe rere, bẹ̃ni kì yio ṣe buburu.
13 Nitorina ogun wọn o di ikógun, ati
ilẹ wọn yio di ahoro: nwọn o kọ́ ile pẹlu,
ṣugbọn nwọn kì yio gbe inu wọn, nwọn o
si gbìn ogbà àjara, ṣugbọn nwọn kì yio
mu ọti-waini inu rẹ̀.
14 Ọjọ nla Oluwa kù si dẹ̀dẹ, o kù si
dẹ̀de, o si nyara kánkan, ani ohùn ọjọ
Oluwa: alagbara ọkọnrin yio sọkun ki-
korò nibẹ̀.
15 Ọjọ na ọjọ ibinu ni, ọjọ iyọnu, ati
ipọnju, ọjọ ofò ati idahoro, ọjọ okùǹkun
ati okùdu, ọjọ kũku ati okunkun biribiri,
16 Ọjọ ipè ati idagìrì si ilu olodi wọnni
ati si iṣọ giga wọnni.
17 Emi o si mu ipọnju wá bá enia, ti
nwọn o ma rìn bi afọju, nitori nwọn ti
dẹṣẹ si Oluwa: ẹjẹ̀ wọn li a o si tú jade bi
ekuru, ati ẹran-ara wọn bi igbẹ.
18 Fàdakà wọn tabi wurà wọn kì yio
lè gbà wọn li ọjọ ìbinu Oluwa; ṣugbọn
gbogbo ilẹ̀ na li a o fi iná ijowu rẹ̀ parun:
nitori on o fi iyara mu gbogbo awọn ti
ngbe ilẹ na kuro.

## ORI 2.

EKÓ ara nyin jọ pọ́, ani, ẹ kójọ pọ̀ ori-
lẹ-ède ti kò nani;
2 Ki a to pa aṣẹ na, ki ọjọ na to kọja
bi iyàngbò, ki gbigboná ibinu Oluwa to
de ba nyin, ki ọjọ ibinu Oluwa ki o to de
ba nyin.
3 Ẹ wá Oluwa, gbogbo ẹnyin ọlọkàn
tutù aiye, ti nṣe idajọ rẹ̀; ẹ wá ododo,
ẹ wá ìwa-pẹ̀lẹ: boya a o pa nyin mọ li
ọjọ ibinu Oluwa.
4 Nitoripe a o kọ̀ Gasa silẹ, Aṣkeloni
yio si dahoro: nwọn o le Aṣdodu jade li
ọsangangan, a o si fà Ekronu tu kuro.
5 Egbe ni fun awọn ẹniti ngbe agbègbe
okun, orilẹ-ède awọn ara Kereti! ọ̀rọ Olu-
wa dojukọ nyin; iwọ Kenaani, ile awọn
ara Filistia, emi o tilẹ pa ọ run, ti ẹnikan
kì yio gbe ibẹ̀ mọ.
6 Agbègbe okun yio si jẹ ibujoko ati agọ
fun awọn olùṣọ agùtan, ati agbo fun agbo-
ẹran.
7 Agbègbe na yio si wà fun iyokù ile
Juda; nwọn o jẹ̀ li ori wọn: ni ile Aṣke-
loni wọnni ni nwọn o dùbulẹ li aṣãlẹ:
nitori Oluwa Ọlọrun wọn yio bẹ̀ wọn wò,
yio si yi igbèkun wọn padà kuro.

Digitized by Google

8 Emi ti gbọ́ ẹgàn Moabu, ati ẹlẹyà
awọn ọmọ Ammoni, nipa eyiti nwọn ti
kẹgàn awọn enia mi, ti nwọn si ti gbe ara
wọn ga si agbègbe wọn.
9 Nitorina bi emi ti wà, li Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi, Ọlọrun Israẹli, Dajudaju
Moabu yio dabi Sodomu, ati awọn ọmọ
Ammoni bi Gomorra, bi titàn wèrepe, ati
bi ihò iyọ, ati idahoro titi lai, iyokù awọn
enia mi o kó wọn, iyokù awọn orilẹ-ède mi
yio si jogun wọn.
10 Eyi ni nwọn o ni nitori igberaga
wọn, nitoripe nwọn ti kẹgàn, nwọn si ti
gbe ara wọn ga si enia Oluwa awọn ọmọ-
ogun.
11 Oluwa yio jẹ ibẹ̀ru fun wọn: nitori
on o mu ki gbogbo òriṣa ilẹ aiye ki o rù;
enia yio si ma sìn i, olukuluku lati ipò rẹ̀
wá, ani gbogbo erekùṣu awọn keferi.
12 Ẹnyin ara Etiopia pẹlu, a o fi idà mi
pa nyin.
13 On o si nà ọwọ́ rẹ̀ si ihà ariwa, yio si
pa Assiria run; yio si sọ Ninefe di ahoro,
ati di gbigbẹ bi aginjù.
14 Agbo-ẹran yio si dùbulẹ li ãrin rẹ̀,
gbogbo ẹranko awọn orilẹ-ède: ati ẹiyẹ òfu
ati õrẹ̀ yio ma gbe atẹrigbà rẹ̀, ohùn wọn
yio kọrin li oju fèrese; idahoro yio wà
ninu iloro: nitoriti on o ṣi iṣẹ kedari silẹ.
15 Eyi ni ilu alayọ̀ na ti o ti joko laina-
ni ti o wi li ọkàn rẹ̀ pe, Emi ni, kò si si
ẹnikan ti mbẹ lẹhìn mi: on ha ti ṣe di
ahoro bayi, ibùgbe fun ẹranko lati dubulẹ
si! olukuluku ẹniti o ba kọja lọdọ rẹ̀ yio
pòṣe yio si mì ọwọ́ rẹ̀.

## ORI 3.

EGBE ni fun ọlọ̀tẹ ati alaimọ́, fun ilu
aninilara nì.
2 On kò fetisi ohùn na; on kò gba ẹkọ́;
on kò gbẹkẹ̀le Oluwa; on kò sunmọ ọdọ
Ọlọrun rẹ̀.
3 Awọn olori rẹ̀ ti o wà lãrin rẹ̀ kiniun
ti nke ramùramù ni nwọn; awọn onidajọ
rẹ̀ ikõkò aṣãlẹ ni nwọn; nwọn kò sán
egungun titi di owurọ̀.
4 Awọn woli rẹ̀ gberaga, nwọn si jẹ ẹlẹ-
tàn enia: awọn alufa rẹ̀ ti ba ibi mimọ́ jẹ:
nwọn ti rú ofin.
5 Oluwa li olõtọ lãrin rẹ̀, kì yio ṣe bu-
buru: li orowurọ̀ li o nmu idajọ rẹ̀ wá si
imọlẹ, kì itase; ṣugbọn awọn alaiṣõtọ kò
mọ itìju.
6 Mo ti ke awọn orilẹ-ède kuro; ile giga
wọn dahoro; mo sọ ita wọnni di ofo, tobẽ
ti ẹnikan kò kọja ihà ibẹ̀: a pa ilu wọnni
run, tobẽ ti kò si enia kan, ti kò si ẹniti
ngbe ibẹ̀.
7 Emi wipe, Lõtọ iwọ o bẹ̀ru mi, iwọ o
gba ẹkọ́; bẽni a kì ba ti ke ibujoko wọn
kuro, bi o ti wù ki mo jẹ wọn ni iyà to:
ṣugbọn nwọn dide ni kùtukùtu, nwọn ba
gbogbo iṣẹ wọn jẹ.
8 Nitorina ẹ duro dè mi, ni Oluwa wi,
titi di ọjọ na ti emi o dide si ohun-ọdẹ:
nitori ipinnu mi ni lati kó awọn orilẹ-ède
jọ, ki emi ki o le kó awọn ilẹ ọba jọ, lati
dà irúnu mi si ori wọn, ani gbogbo ibinu
mi gbigbona: nitori a o fi iná owu mi jẹ
gbogbo aiye run.
9 Nitori nigbana li emi o yi ède mimọ́ si
awọn enia, ki gbogbo wọn ki o le ma pè
orukọ Oluwa, lati fi ọkàn kan sìn i.
10 Lati oke odò Etiopia awọn ẹlẹbẹ̀ mi,
ani ọmọbirin afunká mi, yio mu ọrẹ mi wá.
11 Li ọjọ na ni iwọ kì yio tijú, nitori
gbogbo iṣe rẹ, ninu eyiti iwọ ti dẹṣẹ si mi:
nitori nigbana li emi o mu awọn ti nyọ̀
ninu igberaga rẹ kuro lãrin rẹ, iwọ kì yio
si gberaga mọ li oke mimọ́ mi.
12 Emi o fi awọn otòṣi ati talakà enia
silẹ pẹlu lãrin rẹ, nwọn o si gbẹkẹ̀le orukọ
Oluwa.
13 Awọn iyokù Israeli kì yio hùwa ibi,
bẽni nwọn kì yio sọrọ eke, bẽni a kì yio ri
ahọn arekerekè li ẹnu wọn: ṣugbọn nwọn
o jẹun nwọn o si dubulẹ, ẹnikan kì yio si
dẹruba wọn.
14 Kọrin, iwọ ọmọbirin Sioni; kigbe,
iwọ Israeli; fi gbogbo ọkàn yọ̀, ki inu rẹ
ki o si dùn, iwọ ọmọbirin Jerusalemu.
15 Oluwa ti mu idajọ rẹ wọnni kuro, o
ti tì ọta rẹ jade: ọba Israeli, ani Oluwa,
mbẹ lãrin rẹ: iwọ kì yio si ri ibi mọ.
16 Li ọjọ na a o wi fun Jerusalemu pe,
Iwọ má bẹ̀ru: ati fun Sioni pe, Má jẹ ki
ọwọ́ rẹ ki o dẹ̀.
17 Oluwa Ọlọrun rẹ li agbara li ãrin rẹ̀;
yio gbà ni là, yio yọ̀ li ori rẹ fun ayọ̀; yio
simi ninu ifẹ rẹ̀, yio fi orin yọ̀ li ori rẹ.
18 Emi o kó awọn ti o banujẹ fun ajọ
mimọ́ jọ, awọn ti o jẹ tirẹ, fun awọn ti ẹgàn
rẹ̀ jasi ẹrù.
19 Kiyesi i, nigbana li emi o ṣe awọn ti
npọn ọ li oju: emi a gbà atiro là, emi o si
ṣà ẹniti a le jade jọ; emi o si sọ wọn di ẹni
iyìn ati olokìki ni gbogbo ilẹ ti a ti gàn wọn.
20 Nigbana li emi o mu nyin padà wá,
ani li akokò na li emi o ṣà nyin jọ: nitori
emi o fi orukọ ati iyìn fun nyin lãrin gbo-
gbo enia agbaiye, nigbati emi o yi igbèkun
nyin pada li oju nyin, ni Oluwa wi.

Digitized by Google

# HAGGAI.

## ORI 1.

LI ọdun keji Dariusi ọba, li oṣù kẹfa, li
ọjọ ekini oṣù na, ọ̀rọ Oluwa wá, nipa
ọwọ Haggai woli, sọdọ Serubbabeli ọmọ
Ṣealtieli, bãlẹ Juda, ati sọdọ Joṣua ọmọ
Josedeki, olori alufa, wipe,
2 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi,
Awọn enia wọnyi nsọ pe, Akokò kò ti ide,
akokò ti a ba fi kọ́ ile Oluwa.
3 Nigbana ni ọ̀rọ Oluwa wá nipa Haggai
woli, wi pe,
4 Akokò ha ni fun nyin, ẹnyin, lati ma
gbe ile ọṣọ nyin, ṣugbọn ile yi wà li ahoro?
5 Njẹ nisisiyi bayi li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wipe, Ẹ kiyesi ọ̀na nyin.
6 Ẹnyin ti fọ́n irugbin pupọ̀, ẹ si mu diẹ
wá ile; ẹnyin njẹ, ṣugbọn ẹnyin kò yo:
ẹnyin nmu, ṣugbọn kò tẹ nyin lọrun;
ẹnyin mbora, ṣugbọn kò si ẹniti o gboná;
ẹniti o si ngbowo ọ̀ya o ngbà a sinu ajadi
àpo.
7 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi: Ẹ
kiyesi ọ̀na nyin.
8 Ẹ gùn ori oke-nla lọ, ẹ si mu igi wá,
ki ẹ si kọ́ ile na; inu mi yio si dùn si i, a
o si yìn mi logo, li Oluwa wi.
9 Ẹnyin ti nreti ọ̀pọ, ṣugbọn kiyesi i,
diẹ ni; nigbati ẹnyin si mu u wá ile, mo
si fẹ ẹ danù. Nitori kini? li Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi. Nitori ti ile mi ti o dahoro;
ti olukuluku nyin si nsare fun ile ara rẹ̀.
10 Nitorina ni a ṣe dá ìri ọrun duro lori
nyin, a si da eso ilẹ duro.
11 Mo si ti pè ọdá sori ilẹ, ati sori oke-
nla, ati sori ọkà ati sori ọti-waini titún, ati
sori ororo, ati sori ohun ti ilẹ mu jade, ati
sori enia, ati sori ẹran, ati sori gbogbo iṣẹ
ọwọ ẹni.
12 Nigbana ni Serubbabeli ọmọ Sealti-
eli, ati Joṣua ọmọ Josedeki, olori alufa, pẹlu
gbogbo enia iyokù, gba ohùn Oluwa Ọlọ-
run wọn gbọ́, ati ọ̀rọ Haggai woli, gẹgẹ bi
Oluwa Ọlọrun wọn ti rán a, awọn enia si
bẹ̀ru niwaju Oluwa.
13 Nigbana ni Haggai iranṣẹ Oluwa jiṣẹ
Oluwa fun awọn enia, pe, Emi wà pẹlu
nyin, li Oluwa wi.
14 Oluwa si rú ẹ̀mi Serubbabeli ọmọ
Ṣealtieli, bãlẹ Juda soke, ati ẹ̀mi Joṣua
ọmọ Josedeki, olori alufa, ati ẹmi gbogbo
awọn enia iyokù; nwọn si wá nwọn si ṣiṣẹ
ni ile Oluwa awọn ọmọ-ogun Ọlọrun wọn.
15 Li ọjọ kẹrinlelogun oṣù kẹfà, li ọdun
keji Dariusi ọba.

## ORI 2.

LI oṣù keje, li ọjọ kọkanlelogun oṣù na,
ni ọ̀rọ Oluwa wá nipa ọwọ́ Haggai
woli, wipe,
2 Sọ nisisiyi fun Serubbabeli ọmọ Ṣealti-
eli, bãlẹ Juda, ati fun Joṣua, ọmọ Josedeki,
olori alufa, ati fun awọn enia iyokù, pe,
3 Tali o kù ninu nyin ti o ti ri ile yi li
ogo rẹ̀ akọṣe? bawo li ẹnyin si ti ri i si
nisisiyi? kò ha dàbi asan loju nyin bi a fi
ṣe akawe rẹ̀?
4 Ṣugbọn nisisiyi mura giri, Iwọ Serub-
babeli, li Oluwa wi, ki o si mura giri, Iwọ
Joṣua, ọmọ Josedeki, olori alufa; ẹ si mura
giri gbogbo ẹnyin enia ilẹ na, li Oluwa wi,
ki ẹ si ṣiṣẹ: nitori emi wà pẹlu nyin, li
Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
5 Gẹgẹ bi ọ̀rọ ti mo ba nyin dá majẹmu
nigbati ẹnyin ti Egipti jade wá, bẹ̃ni ẹmi
mi wà lãrin nyin: ẹ máṣe bẹ̀ru.
6 Nitori bayi ni Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi, pe, Ẹrinkan ṣa, nigbà diẹ si i, li emi o
mì awọn ọrun, ati aiye, ati okun, ati iyàn-
gbẹ ilẹ.
7 Emi o si mì gbogbo orilẹ-ède, ifẹ gbo-
gbo orilẹ-ède yio si de: emi o si fi ogo kún
ile yi, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
8 Temi ni fàdaka, temi si ni wurà, li
Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
9 Ogo ile ikẹhìn yi yio pọ̀ jù ti iṣãju lọ,
li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi: nihinyi li
emi o si fi alafia fun ni, li Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi.
10 Li ọjọ ikẹrinlelogun oṣù kẹsan, li
ọdun keji Dariusi, li ọ̀rọ Oluwa wá nipa
Haggai woli, pe,
11 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi;
bère ofin lọwọ awọn alufa nisisiyi, pe,
12 Bi ẹnikan ba rù ẹran mimọ́ ni iṣẹti
aṣọ rẹ̀, ti o si fi iṣẹti aṣọ rẹ̀ kan àkara, tabi



Digitized by Google

àṣaró, tabi ọti-waini, tabi ororo, tabi ẹran-
kẹran, yio ha jẹ mimọ́ ? Awọn alufa si
dahùn wipe, Bẹ̃kọ̀.
13 Haggai si wipe, Bi ẹnikan ti o ba jẹ
alaimọ́ nipa okú ba fi ara kan ọkan ninu
wọnyi, yio ha jẹ alaimọ́ ? Awọn alufa si
dahùn wipe, Yio jẹ alaimọ́.
14 Nigbana ni Haggai dahùn o si wipe,
Bẹ̃ni enia wọnyi ri, bẹ̃ si ni orilẹ-ède yi ri
niwaju mi, li Oluwa wi ; bẹ̃ si li olukuluku
iṣẹ ọwọ wọn ; eyiti nwọn si fi rubọ nibẹ̀ jẹ
alaimọ́.
15 Njẹ nisisiyi, mo bẹ̀ nyin, ẹ rò lati oni
yi de atẹhìnwa, ki a to fi okuta kan le ori
ekeji ninu tempili Oluwa ;
16 Lati ọjọ wọnni wá, nigbati ẹnikan ba
de ibi ile ogun, mẹwa pere ni : nigbati
ẹnikan ba de ibi ifunti lati ba gbọ́n ãdọta
akoto ninu ifunti na, ogún pere ni.
17 Mo fi ìrẹdanù ati imúwòdu ati yìnyin
lù nyin ninu gbogbo iṣẹ ọwọ nyin : ṣugbọn
ẹnyin kò yipadà sọdọ mi, li Oluwa wi.
18 Nisisiyi ẹ rò lati oni lọ de atẹhìnwa,
lati ọjọ ikẹrinlelogun oṣù kẹsan, ani lati
ọjọ ti a ti fi ipilẹ tempili Oluwa sọlẹ, ro o.
19 Eso ha wà ninu abà bi ? Iõtọ, àjara,
ati igi ọ̀pọtọ, ati pomegranate, ati igi olifi,
kò iti so sibẹ̀sibẹ̀ : lati oni lọ li emi o bukún
fun nyin.
20 Ọ̀rọ Oluwa si tún tọ̀ Haggai wá li ọjọ
kẹrinlelogun oṣù na, pe.
21 Sọ fun Serubbabeli, bãlẹ Juda, pe,
emi o mì awọn ọrun ati aiye ;
22 Emi o si bì itẹ awọn ijọba ṣubu, emi
o si pa agbara ijọba keferi run ; emi o si
doju awọn kẹkẹ́ de, ati awọn ti o gùn wọn;
ati ẹṣin ati awọn ẹlẹṣin yio wá ilẹ ; oluku-
luku nipa idà arakọnrin rẹ̀.
23 Li ọjọ na, li Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi, li emi o mu ọ, Iwọ Serubbabeli, iranṣẹ
mi, ọmọ Ṣealtieli, li Oluwa wi, emi o si sọ
ọ di oruka edídi kan: nitoriti mo ti yàn ọ,
li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.

# SEKARIAH.

## ORI 1.

LI oṣù kẹjọ, li ọdun keji Dariusi, li ọ̀rọ
Oluwa tọ̀ Sekariah wá, ọmọ Berekiah
ọmọ Iddo woli, pe,
2 Oluwa ti binu pupọ̀ si awọn baba nyin.
3 Nitorina iwọ wi fun wọn pe, Bayi li
Oluwa awọn ọmọ-ogun wi ; Oluwa awọn
ọmọ-ogun wipe, Ẹ yipadà si mi, emi o si yi-
padà si nyin, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
4 Ẹ má dàbi awọn baba nyin, awọn ti
awọn woli iṣãju ti ké si wipe, Bayi li Olu-
wa awọn ọmọ-ogun wi ; Ẹ yipadà nisisiyi
kuro li ọ̀na buburu nyin, ati kuro ninu
ìwa-buburu nyin : ṣugbọn nwọn kò gbọ́,
bẹ̃ni nwọn kò fetisi ti emi, ni Oluwa wi.
5 Awọn baba nyin, nibo ni nwọn wà ?
ati awọn woli, nwọn ha wà titi aiye ?
6 Ṣugbọn ọ̀rọ mi ati ilàna mi, ti mo pa
li aṣẹ fun awọn iranṣẹ mi woli, nwọn kò ha
fi mu awọn baba nyin ? nwọn si padà nwọn
wipe, Gẹgẹ bi Oluwa awọn ọmọ-ogun ti rò
lati ṣe si wa, gẹgẹ bi ọ̀na wa, ati gẹgẹ bi
iṣe wa, bẹ̃ni o ti ṣe si wa.
7 Li ọjọ kẹrinlelogun oṣù kọkanla, ti iṣe
oṣù Sebati, li ọdun keji Dariusi, li ọ̀rọ
Oluwa tọ̀ Sekariah, ọmọ Berekiah ọmọ
Iddo woli wá, pe,
8 Mo ri li oru, si wò o, ọkọnrin kan
ngun ẹṣin pupa kan, on si duro lãrin awọn
igi mirtili ti o wà ni ibi õji ; lẹhìn rẹ̀ si li
ẹṣin pupa, adíkalà, ati funfun gbe wà.
9 Nigbana ni mo wipe, Kini wọnyi olu-
wa mi ? Angeli ti mba mi sọ̀rọ si wi fun
mi pe, emi o fi ohun ti wọnyi jẹ hàn ọ.
10 Ọkọnrin ti o duro lãrin awọn igi
mirtili si dahùn o si wipe, Wọnyi li awọn
ti Oluwa ti rán lati mã rìn sokè sodò li
aiye.
11 Nwọn si da angeli Oluwa ti o duro
lãrin awọn igi mirtili na lohùn pe, Awa ti
rìn soké sodò já aiye, si kiyesi i, gbogbo
aiye wà ni isimi, o si duro jẹ.
12 Nigbana ni angeli Oluwa na dahùn o
si wipe, Oluwa awọn ọmọ-ogun yio ti pẹ to
ti iwọ kì yio fi ṣãnu fun Jerusalemu, ati
fun awọn ilu-nla Juda, ti iwọ ti binu si li
ãdọrin ọdun wọnyi ?

Digitized by Google

13 Oluwa si fi ọ̀rọ̀ rere ati ọ̀rọ̀ itùnu da
angeli ti mba mi sọ̀rọ̀ lohùn.
14 Angeli ti mba mi sọ̀rọ̀ si wi fun mi
pe, Iwọ kigbe wipe, Bayi li Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi; emi nfi ijowu nla jowu fun
Jerusalemu ati fun Sioni.
15 Emi si binu pupọ̀pupọ̀ si awọn orilẹ-
ède ti o gbe jẹ: nitoripe emi ti binu diẹ,
nwọn si ti kún buburu na lọwọ.
16 Nitorina bayi li Oluwa wi; mo padà
tọ̀ Jerusalemu wá pẹlu ãnu; Oluwa awọn
ọmọ-ogun wipe, a o kọ ile mi sinu rẹ̀, a o si
ta okùn kan jade sori Jerusalemu.
17 Mã ke sibẹ̀ pe, Bayi li Oluwa awọn
ọmọ-ogun wi; A o ma fi ire kún ilu-nla mi
sibẹ̀; Oluwa yio si ma tù Sioni ninu sibẹ̀,
yio si yàn Jerusalemu sibẹ̀.
18 Mo si gbe oju mi soke, mo si ri, si
kiyesi i, iwo mẹrin.
19 Mo si sọ fun angeli ti o ba mi sọ̀rọ̀ pe,
Kini wọnyi? O si da mi lohùn pe, Awọn
wọnyi ni iwo ti o ti tú Juda, Israeli, ati
Jerusalemu ka.
20 Oluwa si fi gbẹnàgbẹnà mẹrin kan
hàn mi.
21 Nigbana ni mo wipe, kini awọn wọnyi
wá ṣe? O si sọ wipe, Awọn wọnyi ni iwo
ti o ti tú Juda ka, tobẹ̃ ti ẹnikẹni kò fi gbe
ori rẹ̀ soke? ṣugbọn awọn wọnyi wá lati
dẹruba wọn, lati le iwo awọn orilẹ-ède jade,
ti nwọn gbe iwo wọn sori ilẹ Juda lati tu
u ka.

## ORI 2.

MO si tun gbe oju mi soke, mo si wò, si
kiyesi i, ọkọnrin kan ti on ti okùn-
iwọ̀n lọwọ rẹ̀.
2 Mo si wipe, Nibọ ni iwọ nlọ? o si wi
fun mi pe, Lati wọ̀n Jerusalemu, lati ri iye
ibù rẹ̀, ati iye gigùn rẹ̀.
3 Si kiyesi i, angeli ti o mba mi sọ̀rọ̀
jade lọ, angeli miran si jade lọ ipade rẹ̀.
4 O si wi fun u pe, Sare, sọ fun ọdọmọ-
kọnrin yi wipe, a o gbe inu Jerusalemu
bi ilu ti kò ni odi nitori ọ̀pọ enia ati ohun-
ọsin inu rẹ̀:
5 Oluwa wipe, Emi o si jẹ odi iná fun u
yika, emi o si jẹ ogo lãrin rẹ̀.
6 Ã! ã! sá kuro ni ilẹ ariwa, ni Oluwa
wi; nitoripe bi afẹfẹ mẹrin ọrun ni mo tu
nyin kakiri, ni Oluwa wi.
7 Sioni, gba ara rẹ là, iwọ ti o mba ọmọ-
birin Babiloni gbe.
8 Nitori bayi ni Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi lẹhin ogo li o ti rán mi si awọn orilẹ-ède ti
nkó nyin: nitori ẹniti o tọ́ nyin, o tọ́ ọmọ
oju rẹ̀.
9 Nitori kiyesi i, emi o gbọ̀n ọwọ mi si
ori wọn, nwọn o si jẹ ikogun fun iranṣẹ
wọn: ẹnyin o si mọ̀ pe, Oluwa awọn ọmọ-
ogun li o rán mi.
10 Kọrin ki o si yọ̀, iwọ ọmọbirin Sioni:
sa wò o, mo de, emi o si gbe ãrin rẹ, ni
Oluwa wi.
11 Ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède ni yio dapọ̀ mọ
Oluwa li ọjọ na, nwọn o si di enia mi;
emi o si gbe ãrin rẹ, iwọ o si mọ̀ pe,
Oluwa awọn ọmọ-ogun li o rán mi si ọ.
12 Oluwa o si jogún Juda iní rẹ̀, ni ilẹ
mimọ́, yio si tun yàn Jerusalemu.
13 Ẹ dakẹ, gbogbo ẹran-ara niwaju
Oluwa: nitori a ji i lati ibùgbe mimọ́ rẹ̀
wá.

## ORI 3.

O SI fi Joṣua olori alufa hàn mi, o duro
niwaju angeli Oluwa, Satani si duro
lọwọ ọtun rẹ̀ lati kọju ijà si i.
2 Oluwa si wi fun Satani pe, Oluwa ba ọ
wi, iwọ Satani; ani Oluwa ti o ti yàn
Jerusalemu, o ba ọ wi: igi iná kọ eyi ti a
mu kuro ninu iná?
3 A si wọ̀ Joṣua li aṣọ ẽri, o si duro
niwaju angeli na.
4 O si dahùn o wi fun awọn ti o duro
niwaju rẹ̀ pe, Bọ aṣọ ẽri nì kuro li ara rẹ̀.
O si wi fun u pe, Wò o, mo mu ki aiṣedẽde
rẹ kuro lọdọ rẹ, emi o si wọ̀ ọ li aṣọ ẹyẹ.
5 Mo si wipe, Jẹ ki wọn fi lawàni mimọ́
wé e li ori. Nwọn si fi lawàni mimọ́ wé e
lori, nwọn si fi aṣọ wọ̀ ọ. Angeli Oluwa si
duro tì i.
6 Angeli Oluwa si tẹnu mọ fun Joṣua
pe,
7 Bayi ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi; bi
iwọ o ba rìn li ọ̀na mi, bi iwọ o ba si pa
aṣẹ mi mọ, iwọ o si ṣe idajọ ilẹ mi pẹlu,
iwọ o si pa ãfin mi mọ pẹlu, emi o si fun
ọ li àye ati rìn lãrin awọn ti o duro yi.
8 Gbọ́ na, iwọ Joṣua olori alufa, iwọ,
ati awọn ẹgbẹ́ rẹ ti o joko niwaju rẹ: ni-
tori ẹni iyanu ni nwọn: nitori kiyesi i,
emi o mu iranṣẹ mi ẸKA, wá.
9 Nitori kiyesi i, okuta ti mo ti gbe
kalẹ niwaju Joṣua; lori okuta kan ni oju
meje o wà: kiyesi i, emi o fin finfin rẹ̀, ni
Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, emi o si mu
aiṣedẽde ilẹ na kuro ni ijọ kan.
10 Oluwa awọn ọmọ-ogun wipe, ni ọjọ
na ni olukuluku yio pe ẹnikeji rẹ̀ sabẹ igi
àjara ati sabẹ igi ọpọ̀tọ.

Digitized by Google

## ORI 4.

ANGELI ti o mba mi sọ̀rọ si tún de, o si ji mi, bi ọkọnrin ti a ji lati oju orun rẹ̀,

2 O si wi fun mi pe, Kini iwọ ri? Mo si wipe, mo wò, si kiyesi i, ọ̀pa fitilà ti gbogbo rẹ̀ jẹ wurà, pẹlu kòjo rẹ̀ lori rẹ̀, pẹlu fitilà meje rẹ̀ lori rẹ̀, ati irọ meje fun fitilà mejeje, ti o wà lori rẹ̀:

3 Igi olifi meji si wà leti rẹ̀, ọkan li apa ọtun kòjo na, ati ekeji li apa osì rẹ̀.

4 Mo si dahùn mo si wi fun angeli ti o mba mi sọ̀rọ, pe, Kini wọnyi, Oluwa mi?

5 Angeli ti o mba mi sọ̀rọ dahùn o si wi fun mi pe, Iwọ kò mọ̀ ohun ti awọn wọnyi jasi? Mo si wipe, Nkò mọ̀, oluwa mi.

6 O si dahùn o si wi fun mi pe, Eyi ni ọ̀rọ Oluwa si Serubbabeli wipe, Kì iṣe nipa ipá, kì iṣe nipa agbara, bikoṣe nipa Ẹmi mi, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.

7 Tani iwọ, Iwọ oke-nla? iwọ o di pẹ̀tẹlẹ niwaju Serubbabeli: on o si fi ariwo mu okuta tenté ori rẹ̀ wá, yio ma kigbe wipe, Ore-ọfẹ, ore-ọfẹ si i.

8 Ọ̀rọ Oluwa si tọ̀ mi wá, wipe,

9 Ọwọ Serubbabeli li o pilẹ ile yi; ọwọ rẹ̀ ni yio si pari rẹ̀; iwọ o si mọ̀ pe, Oluwa awọn ọmọ-ogun li o rán mi si nyin.

10 Ṣugbọn tani ha kẹgàn ọjọ ohun kekere? nitori nwọn o yọ̀, nwọn o si ri iwọ̀n lọwọ Serubbabeli pẹlu meje wọnni; awọn ni oju Oluwa, ti o nsare sihin sọhun ni gbogbo aiye.

11 Mo si dahun, mo si sọ fun u pe, Kini awọn igi olifi meji wọnyi jasi, ti o wà li apá ọtun fitilà ati li apá osì rẹ̀?

12 Mo si tún dahùn, mo si sọ fun u pe, Kini awọn ẹka meji igi olifi wọnyí jasi, ti ntú ororo wurà jade lori wọn lati inu ikòko wurà.

13 O si dahùn, o wi fun mi pe, Iwọ kò mọ̀ ohun ti awọn wọnyi jasi? Mo si wipe, Nkò mọ̀, oluwa mi.

14 O si wipe, Awọn meji wọnyi ni awọn ti a fi ororo yàn, ti o duro tì Oluwa gbogbo aiye.

## ORI 5.

NIGBANA ni mo yipadà, mo si gbe oju mi soke, mo si wò, si kiyesi i, iwe-kiká ti nfò.

2 O si wi fun mi pe, Kini iwọ ri? Emi si dahùn pe, mo ri iwe-kiká ti nfò; gigùn rẹ̀ jẹ ogún igbọnwọ, ibú rẹ̀ si jẹ igbọnwọ mẹwa.

3 O si wi fun mi pe, Eyi ni ègun ti o jade lọ si gbogbo ilẹ aiye: nitori gbogbo awọn ti o ba jale ni a o ke kuro lati ihin lọ nipa rẹ̀; gbogbo awọn ti o ba si bura ni a o ke kuro lati ihin lọ nipa rẹ̀.

4 Emi o mu u jade, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, yio si wọ̀ inu ile olè Iọ, ati inu ile ẹniti o ba fi orukọ mi bura eke: yio si wà li ãrin ile rẹ̀, yio si run u pẹlu igi ati okuta inu rẹ̀.

5 Angeli ti mba mi sọ̀rọ si jade lọ, o si wi fun mi pe, Gbe oju rẹ si oke nisisiyi, ki o si wò nkan yi ti o jade lọ.

6 Mo si wipe, Kini nì? O si wipe, Eyi ni òṣuwọn efà ti o jade lọ. O si wipe, Eyi ni àworan ni gbogbo ilẹ aiye.

7 Si kiyesi i, a gbe talenti ojé soke: obirin kan si niyi ti o joko si ãrin òṣuwọn efa.

8 O si wipe, Eyi ni iwa-buburu. O si jù u si ãrin òṣuwọn efa: o si jù òṣuwọn ojé si ẹnu rẹ̀.

9 Mo si gbe oju mi soke, mo si wò, si kiyesi i, obirin meji jade wá, ẹfũfu si wà ninu iyẹ wọn; nitori nwọn ni iyẹ bi iyẹ àkọ; nwọn si gbe òṣuwọn efa na de agbedemeji aiye on ọrun.

10 Mo si sọ fun angeli ti o mba mi sọ̀rọ pe, Nibo ni awọn wọnyi ngbe òṣuwọn efa na lọ?

11 O si wi fun mi pe, Lati kọ́ ọ ni ile ni ilẹ Ṣinari: a o si fi idi rẹ̀ mulẹ, a o si fi ka ori ipilẹ rẹ̀ nibẹ̀.

## ORI 6.

MO si yipadà, mo si gbe oju mi soke, mo si wò, si kiyesi i, kẹkẹ́ mẹrin jade wá lati ãrin oke-nla meji; awọn oke-nla na si jẹ oke-nla idẹ.

2 Awọn ẹṣin pupa wà ni kẹkẹ́ ekini; ati awọn ẹṣin dudu ni kẹkẹ́ keji;

3 Ati awọn ẹṣin funfun ni kẹkẹ́ kẹta; ati awọn adikalà ati alagbara ẹṣin ni kẹkẹ́ kẹrin.

4 Mo si dahùn mo si wi fun angeli ti mba mi sọ̀rọ pe, Kini wọnyi, oluwa mi?

5 Angeli na si dahùn o si wi fun mi pe, Wọnyi ni awọn ẹmi mẹrin ti ọrun, ti njade lọ kuro ni iduro niwaju Oluwa gbogbo aiye.

6 Awọn ẹṣin dudu ti o wà ninu rẹ̀ jade lọ si ilẹ ariwa; awọn funfun si jade tẹ̀le wọn; awọn adíkalà si jade lọ si ihà ilẹ gusù.

7 Awọn alagbara ẹṣin si jade lọ, nwọn si nwá ọ̀na ati lọ ki nwọn ba le rìn sihin sọhun li aiye; o si wipe, Ẹ lọ, ẹ lọ irìn

Digitized by Google

sihin sọhun li aiye. Nwọn si rin sihin
sọhun li aiye.
8 Nigbana ni on si kọ́ si mi, o si ba mi
sọ̀rọ, wipe, Wò, o, awọn wọnyi ti o lọ
sihà ilẹ ariwa ti mu ẹmi mi parọrọ ni ilẹ
ariwa.
9 Ọ̀RỌ Ọluwa si tọ̀ mi wá, wipe,
10 Mu ninu igbèkun, ninu awọn ti
Heldai, ti Tobijah, ati ti Jedaiah, ti o ti
Babiloni de, ki iwọ si wá li ọjọ kanna, ki
o si wọ ile Josiah ọmọ Sefaniah lọ;
11 Ki o si mu fàdakà ati wurà, ki o si
fi ṣe ade pupọ̀, ki o si gbe wọn kà ori Joṣua
ọmọ Josedeki, olori alufa:
12 Si sọ fun u pe, Bayi ni Oluwa awọn
ọmọ-ogun sọ wipe, Wò ọkọnrin na ti orukọ
rẹ̀ njẹ Ẹ̣KA; yio si yọ ẹka lati abẹ rẹ̀ wá,
yio si kọ́ tempili Oluwa;
13 On ni yio si kọ́ tempili Oluwa; on
ni yio si rù ogo, yio si joko yio si jọba lori
itẹ rẹ̀; on o si jẹ alufa lori itẹ̀ rẹ̀; ìmọ ala-
fia yio si wà lãrin awọn mejeji.
14 Ade wọnni yio si wà fun Helemu, ati
fun Tobijah, ati fun Jedaiah, ati fun Heni
ọmọ Sefaniah, fun iranti ni tempili Oluwa.
15 Awọn ti o jìna rére yio wá ikọle ni
tempili Oluwa, ẹnyin o si mọ̀ pe, Oluwa
awọn ọmọ-ogun ti rán mi si nyin. Yio si
ri bẹ, bi ẹnyin o ba gbà ohùn Oluwa Ọlọ-
run nyin gbọ́ nitõtọ.

## ORI 7.

O SI ṣe li ọdun kẹrin Dariusi ọba, ọ̀rọ
Oluwa tọ̀ Sekariah wá ni ijọ kẹrin oṣù
kẹsan, Kisleu;
2 Nigbati nwọn rán Ṣereseri ati Regem-
meleki, ati awọn enia wọn si ile Ọlọrun
lati wá oju rere Oluwa.
3 Ati lati bá awọn alufa ti o wà ni ile
Oluwa awọn ọmọ-ogun, ati awọn woli sọ̀rọ,
wipe, Ki emi ha sọkun li oṣù karun, ki
emi ya ara mi sọtọ, bi mo ti nṣe lati ọdun
melo wọnyi wá?
4 Nigbana li ọ̀rọ Oluwa awọn ọmọ-ogun
tọ̀ mi wá wipe,
5 Sọ fun gbogbo awọn enia ilẹ na, ati
fun awọn alufa, wipe, Nigbati ẹnyin gba-
wẹ̀ ti ẹ si ṣọ̀fọ li oṣù karun ati keje, ani fun
ãdọrin ọdun wọnni, ẹnyin ha gbawẹ̀ si mi
rara, ani si emi?
6 Nigbati ẹ si jẹ, ati nigbati ẹ mu, fun
ara nyin ki ẹnyin ha jẹ, ati fun ara nyin ki
ẹnyin ha mu?
7 Wọnyi ki ọ̀rọ ti Oluwa ti kigbe lati
ọdọ awọn woli iṣãju wá, nigbati a ngbe
Jerusalemu, ti o si wà li alafia, pẹlu awọn
ilu rẹ̀ ti o yi i ka kiri, nigbati a ngbe gusù
ati pẹtẹlẹ?
8 Ọrọ Oluwa si tọ̀ Sekariah wá, wipe,
9 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun sọ wipe,
Dá idajọ otitọ, ki ẹ si ṣe ãnu ati iyọ́nu olu-
kuluku si arakọnrin rẹ̀.
10 Má si ṣe ni opó lara, tabi alainibaba,
alejo, tabi talakà; ki ẹnikẹni ninu nyin ki
o máṣe gbèro ibi li ọkàn si arakọnrin rẹ̀.
11 Ṣugbọn nwọn kọ̀ lati gbọ́, nwọn si
gún ejika, nwọn si di eti wọn, ki nwọn ki
o má bà gbọ́.
12 Ani nwọn ṣe aiya wọn bi okuta ada-
manti, ki nwọn ki o má ba gbọ́ ofin, ati
ọ̀rọ ti Oluwa awọn ọmọ-ogun ti fi ẹmi rẹ̀
rán nipa ọwọ awọn woli iṣãju wá: ibinu
nla si de lati ọdọ Ọluwa awọn ọmọ-ọgun wá.
13 O si ṣe, gẹgẹ bi o ti kigbe, ti nwọn kọ̀
si fẹ igbọ́, bẹ̃ni nwọn kigbe, ti emi kọ̀ si fẹ
igbọ́, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
14 Mo si fi ãja tú wọn ka si gbogbo
orilẹ-ède ti nwọn kọ̀ mọ̀. Ilẹ na si dahoro
lẹhin wọn, ti ẹnikẹni kọ̀ là a kọja tabi ki
o pada bọ̀: nwọn si sọ ilẹ ãyò na dahoro.

## ORI 8.

ỌRỌ Oluwa awọn ọmọ-ogun si tun tọ̀ mi
wá, wipe,
2 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi;
owu nlanla ni mo jẹ fun Sioni, ikọnnu
nlanla ni mo fi jowu fun u.
3 Bayi li Oluwa wi; Mo ti yipada si
Sioni, emi o si gbe ãrin Jerusalemu: a o si
pè Jerusalemu ni ilunla otitọ; ati oke-nla
Oluwa awọn ọmọ-ogun, oke-nla mimọ́ nì.
4 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi,
arugbo ọkọnrin, ati arugbo obirin, yio sa
gbe igboro Jerusalemu, ati olukuluku ti on
ti ọ̀pa li ọwọ rẹ̀ fun ogbó.
5 Igboro ilu yio si kún fun ọmọde-kọn-
rin, ati ọmọdebirin, ti nṣire ni ita wọn.
6 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi pe,
bi o ba ṣe iyanu li oju iyokù awọn enia yi
li ọjọ wọnyi, iba jẹ iyanu li oju mi pẹlu bi?
li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
7 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi
pe, Kiye si i, emi o gbà awọn enia mi kuro
ni ilẹ gabasi, ati kuro ni ilẹ yama;
8 Emi o si mu wọn wá, nwọn o si ma
gbe ãrin Jerusalemu: nwọn o si jẹ enia
mi, emi o si jẹ Ọlọrun wọn, li otitọ, ati li
ododo.
9 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi pe,
Jẹ ki ọwọ nyin ki o le, ẹnyin ti ngbọ́ ọ̀rọ
wọnyi li ọjọ wọnyi li ẹnu awọn woli ti o wà

Digitized by Google

li ọjọ ti a fi ipilẹ ile Oluwa awọn ọmọ-ogun
lelẹ, ki a ba le kọ́ tempili.
10 Nitori pe ṣãju ọjọ wọnni ọya enia kò
to nkan, bẹ̃ni ọ̀ya ẹran pẹlu; bẹ̃ni kò si
alafia fun ẹniti njade lọ, tabi ẹniti nwọle
bọ̀, nitori ipọnju na: nitori mo doju gbo-
gbo enia olukuluku kọ aladugbo rẹ̀.
11 Ṣugbọn nisisiyi emi kì yio ṣe si iyo-
kù awọn enia yi gẹgẹ bi ti ìgba atijọ wọnni,
li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
12 Nitori irugbin yio gbilẹ: àjara yio so
eso rẹ̀, ilẹ yio si hù ọ̀pọlọpọ nkan rẹ̀ jade,
awọn ọrun yio si mu ìri wọn wá: emi o si
mu ki awọn iyokù enia yi ni gbogbo nkan
wọnyi.
13 Yio si ṣe, gẹgẹ bi ẹnyin ti jẹ egún
lãrin awọn keferi, ẹnyin ile Juda, ati ile
Israeli, bẹ̃li emi o gbà nyin silẹ; ẹnyin o
si jẹ ibukún: ẹ má bẹ̀ru, ṣugbọn jẹ ki ọwọ
nyin ki o le.
14 Nitori bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi; gẹgẹ bi mo ti rò lati ṣẹ́ nyin niṣẹ,
nigbati awọn baba nyin mu mi binu, li
Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, ti emi kò si
ronupiwadà.
15 Bẹ̃li emi si ti rò ọjọ wọnyi lati ṣe
rere fun Jerusalemu, ati fun ile Juda: ẹ
má bẹ̀ru.
16 Wọnyi ni nkan ti ẹnyin o ṣe: Ẹ sọ̀rọ
otitọ, olukuluku si ẹnikeji rẹ̀; ṣe idajọ
tõtọ ati alafia ni bodè nyin wọnni.
17 Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikan ki o rò ibi li
ọkàn rẹ̀ si ẹnikeji rẹ̀; ẹ má fẹ ibura eke:
nitori gbogbo wọnyi ni mo korira, li Olu-
wa wi.
18 Ọ̀rọ Oluwa awọn ọmọ-ogun si tọ̀ mi
wá wipe,
19 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi pe;
Ãwẹ̀ oṣù kẹrin, ati ti oṣù karun, ati ãwẹ̀
oṣù keje, ati ti ẹkẹwa, yio jẹ ayọ̀, ati didùn
inu, ati apejọ ariya fun ile Juda; nitorina
ẹ fẹ́ otitọ ati alafia.
20 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi pe;
Awọn enia yio sa tún wá, ati ẹniti yio gbe
ilu-nla pipọ.
21 Awọn ẹniti ngbe ilu-nla kan yio lọ si
omiran, wipe, Ẹ jẹ ki a yára lọ igbadura
niwaju Oluwa, ati lati wá Oluwa awọn
ọmọ-ogun: emi pẹlu o si lọ.
22 Nitõtọ ọ̀pọlọpọ enia, ati awọn alagba-
ra orilẹ-ède yio wá lati wá Oluwa awọn
ọmọ-ogun ni Jerusalemu; ati lati gbadura
niwaju Oluwa.
23 Bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi pe;
li ọjọ wọnni yio ṣẹ, ni ọkọnrin mẹwa lati
inu gbogbo ède ati orilẹ-ède yio di i mú,
ani yio di eti aṣọ ẹniti iṣe Ju mu, wipe, A
o ba ọ lọ, nitori awa ti gbọ́ pe, Ọlọrun wà
pẹlu rẹ.

## ORI 9.

Ọ̀RỌ-ÌMỌ ọ̀rọ Oluwa ni ilẹ Hadraki,
Damasku ni yio si jẹ ibi isimi rẹ̀:
nitori oju Oluwa mbẹ lara enia, ati lara
gbogbo ẹ̀ya Israeli.
2 Ati Hamati pẹlu yio ṣe ãla rẹ̀: Tire
ati Sidoni bi o tilẹ ṣe ọlọgbọ́n gidigidi.
3 Tire si mọ odi lile fun ara rẹ̀, o si ko
fàdakà jọ bi ekuru, ati wurà daradara bi
ẹrẹ̀ ita.
4 Kiye si i, Oluwa yio tá a nù, yio si
kọlu ipá rẹ̀ ninu okun; a o si fi iná jẹ ẹ
run.
5 Aṣkeloni yio ri i, yio si bẹ̀ru; Gasa
pẹlu yio ri i, yio si kãnu gidigidi, ati Ekro-
ni: nitori oju o tì ireti rẹ̀; ọba yio si ṣe-
gbe kuro ni Gasa, a kì o si gbe Aṣkeloni.
6 Ọmọ alè yio si gbe inu Aṣdodi, emi o
si ke irira awọn Filistini kuro.
7 Emi o si mu ẹjẹ rẹ̀ kuro li ẹnu rẹ̀, ati
ohun irira rẹ̀ wọnni kuro lãrin ehín rẹ̀:
ṣugbọn ẹniti o kù, ani on na yio jẹ ti Ọlọ-
run wa, yio si jẹ bi bãlẹ kan ni Juda, ati
Ekroni bi Jebusi.
8 Emi o si dó yi ilẹ mi ka nitori ogun,
nitori ẹniti nkọja lọ, ati nitori ẹniti npada
bọ̀: kò si aninilara ti yio là wọn já mọ:
nitori nisisiyi ni mo fi oju mi ri.
9 Yọ̀ gidigidi, iwọ ọmọbirin Sioni; ho,
Iwọ ọmọbirin Jerusalemu: kiye si i, Ọba
rẹ mbọ̀wá sọdọ rẹ: ododo li on, o si ni igba-
là; o ni irẹlẹ, o si ngùn kẹtẹkẹtẹ, ani ọmọ
kẹtẹkẹtẹ.
10 Emi o si ke kẹkẹ́ kuro ni Efraimu,
ati ẹṣin kuro ni Jerusalemu, a o si ké ọrun
ogun kuro: yio si sọ̀rọ alafia si awọn ke-
feri: ijọba rẹ̀ yio si jẹ lati okun de okun,
ati lati odo titi de opin aiye.
11 Ni tirẹ pẹlu, emi o fi ẹjẹ majẹmu rẹ
rán awọn igbèkun rẹ jade kuro ninu ihò ti
kò li omi.
12 Ẹ pada si odi agbara, ẹnyin onde
ireti: ani loni yi emi sọ pe, emi o san a
fun ọ ni igbàmeji.
13 Nitori mo fa Juda le bi ọrun mi, mo
si fi Efraimu kún u, mo si gbe awọn ọmọ
rẹ ọkọnrin dide, iwọ Sioni, si awọn ọmọ rẹ
ọkọnrin, iwọ ilẹ Griki, mo sọ ọ bi idà
alagbara.
14 Oluwa yio si fi ara rẹ̀ hàn lori wọn,
ọfà rẹ̀ yio si jade lọ bi mànamána: Oluwa

Digitized by Google

Ọlọrun yio si fun ipè, yio si lọ ti on ti ẹ̀jà gusù.

15 Oluwa awọn ọmọ-ogun yio dãbo bò wọn: nwọn o si jẹ ni run, nwọn o si tẹ̀ okuta kànna-kànna mọlẹ; nwọn o si mu, nwọn o si pariwo bi nipa ọti-waini; nwọn o si kún bi ọpọ́n, ati bi awọn igun pẹpẹ.

16 Oluwa Ọlọrun wọn yio si gbà wọn là li ọjọ na bi agbo enia rẹ̀: nitori nwọn o dabi awọn okuta ade, ti a gbe soke bi àmi lori ilẹ rẹ̀.

17 Nitori ore rẹ̀ ti tobi to, ẹwà rẹ̀ si ti pọ̀ to! ọkà yio mu ọdọmọkọnrin darayá, ati ọti-waini titún yio mu awọn ọdọmọbirin ṣe bẽ pẹlu.

## ORI 10.

E BÈRE òjo nigba arọ̀kuro li ọwọ Oluwa; Oluwa yio kọ mànamána, yio si fi ọ̀pọ òjo fun wọn, fun olukuluku koriko ni pápa.

2 Nitori awọn oriṣa ti nsọ̀rọ asan, awọn alafọṣẹ si ti ri eké, nwọn si ti rọ́ alá eké; nwọn ntù ni ni inu lasan, nitorina nwọn ba ti wọn lọ bi ọwọ́ ẹran, a ṣẹ wọn niṣẹ, nitori darandaran kò si.

3 Ibinu mi ru si awọn darandaran, mo si jẹ awọn ewurẹ ni iyà; nitori Oluwa awọn ọmọ-ọgun ti bẹ̀ agbo rẹ̀ ile Juda wò, o si fi wọn ṣe bi ẹṣin rẹ̀ daradara li ogun.

4 Lati ọdọ rẹ̀ ni igun ti jade wá, lati ọdọ rẹ̀ ni iṣo ti wá, lati ọdọ rẹ̀ ni ọrun ogun ti wá, lati ọdọ rẹ̀ ni awọn akonişiṣẹ gbogbo ti wá.

5 Nwọn o si dabi awọn alagbara, ti ntẹ̀ ẹrẹ̀ ita nì mọlẹ li ogun: nwọn o si jagun, nitori Oluwa wà pẹlu wọn, nwọn o si doju ti awọn ti ngùn ẹṣin.

6 Emi o si mu ile Juda le, emi o si gbà ile Josefu là, emi o si tún mun wọn joko; nitori mo ti ṣãnu fun wọn, nwọn o si dabi ẹnipe emi kò ti ta wọn nù: nitori emi ni Oluwa Ọlọrun wọn, emi o si gbọ́ ti wọn.

7 Efraimu yio si ṣe bi alagbara, ọkàn wọn yio si yọ̀ bi ẹnipe nipa ọti-waini: ani awọn ọmọ wọn yio ri i, nwọn o si yọ̀, inu wọn o si dùn si Oluwa.

8 Emi o kọ si wọn, emi o si ṣà wọn jọ; nitori emi ti rà wọn pada: nwọn o si rẹ̀ si i gẹgẹ bi nwọn ti nrẹ̀ si i ri.

9 Emi o si gbìn wọn lãrin awọn enia: nwọn o si ranti mi ni ilẹ jijin; nwọn o si wà pẹlu awọn ọmọ wọn, nwọn o si tún pada.

10 Emi o si tún mu wọn pada kuro ni ilẹ Egipti pẹlu, emi o si ṣà wọn jọ kuro ni ilẹ Assiria: emi o si mu wọn wá si ilẹ Gileadi ati Lebanoni; a kì yio si ri àye fun wọn.

11 Yio si là okun wahala ja, yio si lù riru omi ninu okun, gbogbo ibu odò ni yio si gbẹ, a o si rẹ̀ igberaga Assiria silẹ, ọpa alade Egipti yio si lọ kuro.

12 Emi o si mu wọn le ninu Oluwa; nwọn o si rìn soke rìn sodò li orukọ rẹ̀, ni Oluwa wi.

## ORI 11.

SI ilẹkun rẹ wọnni silẹ, Iwọ Lebanoni, ki iná ba le jẹ igi kedari rẹ run.

2 Hu, igi firi; nitori igi kedari ṣubu; nitori ti a ba awọn alagbara jẹ: hu, ẹnyin igi oaku ti Baṣani, nitori a ke igbo ajara lulẹ.

3 Ohùn igbe awọn oluṣọ agutan; nitori ogo wọn bajẹ: ohùn bibu awọn ọmọ kiniun; nitori ogo Jordani bajẹ.

4 Bayi li Oluwa Ọlọrun mi wi; Bọ́ ọwọ́-ẹran abọ́pa.

5 Ti awọn oluwa wọn npa wọn, ti nwọn kò si kà ara wọn si pe nwọn jẹbi; ati awọn ti ntà wọn wipe, Ibukún ni fun Oluwa, nitoriti mo di ọlọrọ̀: awọn oluṣọ agutan wọn kò si ṣãnu wọn.

6 Nitori emi kì yio ṣãnu fun awọn ara ilẹ na mọ, li Oluwa wi; si kiye si i, emi o fi olukuluku enia le aladugbo rẹ̀ lọwọ, ati le ọwọ ọba rẹ̀: nwọn o si fọ́ ilẹ na, emi kì yio si gbà wọn lọwọ wọn.

7 Emi o si bọ́ ẹran abọ́pa, ani ẹnyin otoṣi ninu ọwọ́ ẹran. Mo si mu ọpa meji sọdọ; mo pe ọkan ni Ẹwà, mo si pe ekeji ni Amure; mo si bọ́ ọwọ́-ẹran na.

8 Oluṣọ-agutan mẹta ni mo si ke kuro li oṣu kan; ọkàn mi si korira wọn, ọkàn wọn pẹlu si korira mi.

9 Mo si wipe, emi kì yio bọ nyin: eyi ti nkú lọ, jẹ ki o kú; eyi ti a o ba si ke kuro, jẹ ki a ke e kuro; ki olukuluku ninu awọn iyokù jẹ ẹran-ara ẹnikeji rẹ̀.

10 Mo si mu ọpa mi, ani Ẹwà, mo si ṣẹ ẹ si meji, ki emi ba le dà majẹmu mi ti mo ti ba gbogbo awọn enia nì da.

11 O si dá li ọjọ na; bẽni awọn otoṣi ninu ọwọ́-ẹran nì ti o duro tì mi mọ̀ pe, ọrọ Oluwa ni.

12 Mo si wi fun wọn pe, Bi o ba dara li oju nyin, ẹ fun mi ni owo-ọ̀ya mi: bi bẽkọ, ẹ jọwọ rẹ̀. Bẽni nwọn wọn ọgbọ̀n owo fadakà fun iye mi.

13 Oluwa si wi fun mi pe, Sọ ọ si amọkòko: iye daradara na ti nwọn yọwó mi

si. Mo si mu ọgbọ̀n owo fadakà na, mo si sọ wọn si amọkòko ni ile Oluwa.

14 Mo si ṣẹ ọpa mi keji, ani Amure, si meji, ki emi ki o le yà ibatan ti o wà lãrin Juda ati lãrin Israeli.

15 Oluwa si wi fun mi pe, Tún mu ohun-elò oluṣọ-agutan aṣiwere kan sọdọ rẹ.

16 Nitori kiye si i, Emi o gbe oluṣọ-agutan kan dide ni ilẹ na, ti kì yio bẹ̀ awọn ti o ṣegbé wò, ti kì yio si wá eyi ti o yapa: ti kì yio ṣe awotan eyi ti o ṣẹ́, tabi kì o bọ́ awọn ti o duro jẹ: ṣugbọn on o jẹ ẹran eyi ti o li ọ̀ra, yio si fa ẽkanna wọn ya pẹrẹpẹ̀rẹ.

17 Egbe ni fun oluṣọ-agutan asan na ti o fi ọwọ́-ẹran silẹ! idà yio wà li apá rẹ̀, ati li oju ọ̀tun rẹ̀: apá rẹ̀ yio gbẹ patapata, oju ọ̀tun rẹ̀ yio si ṣõkùnkun biribiri.

## ORI 12.

ỌRỌ-ÌMỌ ọ̀rọ Oluwa fun Israeli, li Oluwa wi, ẹni ti o nnà awọn ọrun, ti o si fi ipilẹ aiye sọlẹ, ti o si mọ ẹmi enia ti mbẹ ni inu rẹ̀.

2 Kiye si i, emi o sọ Jerusalemu di ago iwarìri si gbogbo enia yika, nigbati nwọn o do tì Juda ati Jerusalemu.

3 Li ọjọ na li emi o sọ Jerusalemu di ẹrù okuta fun gbogbo enia: gbogbo awọn ti o ba si fi dẹrù pa ara wọn li a o ke si wẹwẹ, bi gbogbo awọn orilẹ-ède aiye tilẹ ko ara wọn jọ si i.

4 Li ọjọ na, ni Oluwa wi, li emi o fi itagìri lù gbogbo ẹṣin, ati fi wère lu ẹniti ngùn u; emi o si ṣi oju mi si ile Juda, emi o si bu ifọju lù gbogbo ẹṣin ti enia na.

5 Ati awọn bãlẹ Juda yio si wi li ọkàn wọn pe, Awọn ara Jerusalemu li agbara mi nipa Oluwa Ọlọrun wọn.

6 Li ọjọ na li emi o ṣe awọn bãlẹ Juda bi ãrò iná kan lãrin igi, ati bi ètufu iná lãrin ití; nwọn o si jẹ gbogbo awọn enia run yika lapa ọ̀tun ati lapa osi: a o si tun ma gbe Jerusalemu ni ipo rẹ̀, ani Jerusalemu.

7 Oluwa pẹlu yio kọ́ tète gba agọ Juda là na, ki ogo ile Dafidi ati ogo awọn ara Jerusalemu ma bà gbe ara wọn ga si Juda.

8 Li ọjọ na li Oluwa yio dãbò bò awọn ti ngbe Jerusalemu; ẹniti o ba si ṣe ailera ninu wọn li ọjọ na yio dabi Dafidi; ile Dafidi yio si dabi Ọlọrun, bi angeli Oluwa niwaju wọn.

9 Yio si ṣe li ọjọ na, emi o wá lati pa gbogbo awọn orilẹ-ède run ti o wá kọjuja si Jerusalemu.

10 Emi o si tú ẹmi ore-ọfẹ ati ẹbẹ sori ile Dafidi ati sori Jerusalemu: nwọn o si ma wò mi ẹniti nwọn ti gún li ọ̀kọ, nwọn o si ma ṣọ̀fọ rẹ̀, gẹgẹ bi enia ti nṣọ̀fọ fun ọmọ ọkọnrin rẹ̀ kanṣoṣo, nwọn o si wà ni ibanujẹ, bi ẹniti mbanujẹ fun akọbi rẹ̀.

11 Li ọjọ na li ọ̀fọ nlanlà yio wà ni Jerusalemu, gẹgẹ bi ọ̀fọ Hadadrimmoni li afonifoji Megiddoni.

12 Ilẹ na yio ṣọ̀fọ, idile idile lọtọ̀tọ; idile Dafidi lọ́tọ̀; ati awọn aya wọn lọ́tọ̀: idile Natani lọ́tọ̀, ati awọn aya wọn lọtọ̀.

13 Idile Lefi lọ́tọ̀, ati awọn aya wọn lọ́tọ̀; idile Ṣimei lọ́tọ̀, ati awọn aya wọn lọ́tọ̀.

14 Gbogbo awọn idile ti o kù, idile idile lọtọ̀tọ, ati awọn aya wọn lọ́tọ̀.

## ORI 13.

LI ọjọ na isun kan yio ṣi silẹ fun ile Dafidi ati fun awọn ara Jerusalemi, fun ẹ̀ṣẹ ati fun ìwa aimọ́.

2 Yio si ṣe li ọjọ na, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, li emi o ke orukọ awọn ọ̀riṣa kuro ni ilẹ na, a kì yio si ranti wọn mọ: ati pẹlu emi o mu awọn woli ati awọn ẹmi aimọ́ kọja kuro ni ile na.

3 Yio si ṣe, nigbati ẹnikan yio sọtẹlẹ sibẹ̀, ni baba rẹ̀ ati iya rẹ̀ ti o bi i yio wi fun u pe, Iwọ kì yio yè: nitori iwọ nsọ̀rọ eké li orukọ Oluwa: ati baba rẹ̀ ati iya rẹ̀ ti o bi i yio gún u li agúnyọ nigbati o ba sọtẹlẹ.

4 Yio si ṣe li ọjọ na, oju yio tì awọn woli olukulukù nitori iran rẹ̀, nigbati on ba ti sọtẹlẹ; bẽni nwọn kì yio si wọ̀ aṣọ onirun lati tan ni jẹ:

5 Ṣugbọn on o wipe, Emi kì iṣe woli, agbẹ̀ li emi; nitori enia li o ni mi bi iranṣẹ lati igbà ewe mi wá.

6 Ẹnikan o si wi fun u pe, Ọgbẹ́ kini wọnyi li ọwọ rẹ? On o si dahùn pe, Wọnyi ni a ti ṣá mi ni ile awọn ọrẹ́ mi.

7 Dide, iwọ idà, si olùṣọ-agùtan mi, ati si ẹniti iṣe ẹnikeji mi, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi; kọlù olùṣọ-agùtan, awọn àgutan a si tuká: emi o si yi ọwọ mi si awọn kékèké.

8 Yio si ṣe, ni gbogbo ilẹ, li Oluwa wi, a o ké apá meji ninu rẹ̀ kuro yio si kú; ṣugbọn apá kẹta yio kù ninu rẹ̀.

9 Emi o si mu apá kẹta na là ãrin iná, emi o si yọ́ wọn bi a ti yọ́ fàdakà, emi o si dán wọn wò, bi a ti idán wura wò: nwọn o si pè orukọ mi, emi o si gbọ́ wọn: emi o

Digitized by Google

wipe, Awọn enia mi ni: awọn o si wipe, Oluwa li Ọlọrun mi.

## ORI 14.

KIYESI i, ọjọ Oluwa mbọ̀, a o si pin ikogun rẹ lãrin rẹ.
2 Nitori emi o kó gbogbo orilẹ-ède jọ si
Jerusalemu fun ogun; a o si kó ilu na, a o
si kó awọn ile, a o si bà awọn obirin jẹ,
abọ̀ ilu na yio lọ si igbèkun, a kì yio si ké
iyokù awọn enia na kuro ni ilu na.
3 Nigbana ni Oluwa yio jade lọ, yio si
ba awọn orilẹ-ède wọnni jà, gẹgẹ bi iti ijà
li ọjọ ogun.
4 Ẹsẹ̀ rẹ̀ yio si duro li ọjọ na lori oke
Olifi, ti o wà niwaju Jerusalemu ni gabasi,
oke Olifi yio si là meji si ihà gabasi ati si
ihà yama, afonifojì nlanla yio wà: idajì
oke na yio si ṣi sihà ariwa, ati idajì rẹ̀
siha gusu.
5 Ẹnyin o si sá si afonifojì oke mi wọnni:
nitoripe afonifoji oke na yio de Asali:
nitõtọ, ẹnyin o sa bi ẹ ti sa fun isẹ̀lẹ nì li
ọjọ Ussiah ọba Juda: Oluwa Ọlọrun mi
yio si wá, ati gbogbo awọn Ẹni-mimọ́ pẹlu
rẹ.
6 Yio si ṣẹ li ọjọ na, imọlẹ kì yio mọ́,
bẽni kì yio ṣõkùnkun.
7 Ṣugbọn yio jẹ ọjọ kan mimọ̀ fun Oluwa,
kì iṣe ọsan, kì iṣe oru; ṣugbọn yio ṣe
pe, li aṣãlẹ imọlẹ yio wà.
8 Yio si ṣe li ọjọ na, omi iyè yio ti Jerusalemu
ṣàn lọ; idajì wọn sihà okun gabasi,
ati idajì wọn sihà okun ẹhìn: nigbà ẹrun
ati nigbà otutù ni yio ri bẹ̃.
9 Oluwa yio si jọba lori gbogbo aiye: li
ọjọ na ni Oluwa kan yio wà, orukọ rẹ̀ yio si
jẹ ọkan.
10 A o yi gbogbo ilẹ padà bi pẹtẹlẹ kan
lati Geba de Rimmoni lapa gusu Jerusalemu:
a o si gbe e soke, yio si gbe ipò rẹ̀,
lati ibode Benjamini titi de ibi ibode ekini,
de ibode igun nì, ati lati ile-iṣọ Hananeeli
de ibi ifunti waini ọba.
11 Enia yio si ma gbe ibẹ̀, kì yio si si
iparun yányán mọ; ṣugbọn a o ma gbe
Jerusalemu lailewu.
12 Eyi ni yio si jẹ àrun ti Oluwa yio fi
kọlu gbogbo awọn enia ti o ti ba Jerusalemu
ja; ẹran-ara wọn yio rù nigbati wọn duro
li ẹsẹ̀ wọn, oju wọn yio si rà ni ihò wọn,
ahọn wọn yio si sọkì li ẹnu wọn.
13 Yio si ṣe li ọjọ na, irọkẹ̀kẹ nla lati
ọdọ Oluwa wá yio wà lãrin wọn; nwọn o
si dì ọwọ ara wọn mu, ọwọ rẹ̀ yio si dide si
ọwọ ẹnikeji rẹ̀.
14 Juda pẹlu yio si jà ni Jerusalemu;
ọrọ̀ gbogbo awọn keferi ti o wà kakiri li a
o si kojọ, wurà, ati fàdakà, ati aṣọ li ọpọlọpọ.
15 Bẽni àrun ẹṣin, ibãka, ràkumi, ati ti
kẹtẹkẹtẹ, yio si wà, ati gbogbo ẹranko ti
mbẹ ninu agọ wọnyi gẹgẹ bi àrun yi.
16 Yio si ṣe, olukuluku, ẹniti o kù ninu
gbogbo awọn orilẹ-ède ti o dide si Jerusalemu
yio ma goke lọ lọdọdun lati sìn Ọba,
Oluwa awọn ọmọ-ogun, ati lati pa àse agọ
wọnni mọ.
17 Yio si ṣe, ẹnikẹni ti kì yio goke wá
ninu gbogbo idile aiye si Jerusalemu lati
sìn Ọba, Oluwa awọn ọmọ-ogun, fun wọn
ni òjo kì yio rọ̀.
18 Bi idile Egipti kò ba si goke lọ, ti
nwọn kò si wá, ti kò ni òjo; àrun na yio wà,
ti Oluwa yio fi kọlù awọn keferi ti kò goke
wá lati pa àse agọ na mọ.
19 Eyi ni yio si jẹ iyà Egipti, ati iyà
gbogbo orilẹ-ède ti kò goke wá lati pa àse
agọ mọ.
20 Li ọjọ na ni MIMỌ SI OLUWA yio
wà lara ṣaworo ẹṣin; ati awọn ikòko ni ile
Oluwa yio si dàbi awọn ọpọ́n wọnni niwaju
pẹpẹ.
21 Nitõtọ, gbogbo ikòko ni Jerusalemu
ati ni Juda yio jẹ mimọ́ si Oluwa awọn
ọmọ-ogun: ati gbogbo awon ti nrubọ yio
wá, nwọn o si gbà ninu wọn, nwọn o si bọ̀
ninu rẹ̀: li ọjọ na ni ara Kenaani kì yio si
si mọ ni ile Oluwa awọn ọmọ-ogun.

Digitized by Google

# MALAKI.

## ORI 1.

ỌRỌ-ÌMỌ ọrọ Oluwa si Israeli nipa ọwọ
Malaki.
2 Emi ti fẹ nyin, li Oluwa wi. Ṣugbọn
ẹnyin wipe, Ninu kili o fẹ wa? Arakọnrin
Jakobu ki Esau iṣe? li Oluwa wi: bẹli emi
sa fẹ Jakobu,
3 Mo si korira Esau, mo si sọ awọn oke-
nla rẹ ati ilẹ nini rẹ di ahoro fun awọn
dragoni aginjù.
4 Nitori Edomu wipe, A run wa tan,
ṣugbọn awa o padà, ã si kọ ibùgbe ahoro
wọnni; bayi li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi:
Nwọn o kọ, ṣugbọn emi o wo lulẹ; Nwọn
o si pe wọn ni, Agbègbe ìwa buburu, ati
awọn enia ti Oluwa ni ikọnnu si titi lai.
5 Oju nyin o si ri, ẹnyin o si wipe, A o
gbe Oluwa ga lati oke agbègbe Israeli wá.
6 Ọmọ a ma bọla fun baba, ati ọmọ-ọdọ
fun oluwa rẹ: njẹ bi emi ba ṣe baba, ọla
mi ha da? bi emi ba si ṣe oluwa, ẹru mi ha
da? li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi fun nyin:
Ẹnyin alufa, ti ngàn orukọ mi. Ẹnyin si
wipe, Ninu kini awa fi kẹgàn orukọ rẹ?
7 Ẹnyin fi akarà aimọ́ rubọ lori pẹpẹ mi;
ẹnyin si wipe, Ninu kini li awa ti sọ ọ di
aimọ́? Ninu eyi ti ẹnyin wipe, Tabili
Oluwa di ohun ẹgàn.
8 Bi ẹnyin ba si fi eyi ti oju rẹ fọ́ rubọ,
ibi kọ́ eyini? bi ẹnyin ba si fi amúkun ati
olokunrùn rubọ, ibi kọ́ eyini? mu u tọ
bãlẹ rẹ lọ nisisiyi; inu rẹ yio ha dùn si ọ,
tabi yio ha kà ọ si? li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi.
9 Njẹ nisisiyi, mo bẹ nyin, ẹ bẹ Ọlọrun
ki o ba le ṣe ojurere si wa: lati ọwọ nyin li
eyi ti wá: on o ha kà nyin si? li Oluwa
awọn ọmọ-ogun wi.
10 Ta si ni ninu nyin ti yio se ilẹkun?
bẹ̃li ẹnyin kò da iná asan lori pẹpẹ mi mọ.
Emi kò ni inu-didùn si nyin, li Oluwa
awọn ọmọ-ogun wi, bẹ̃li emi kì yio gba ọrẹ
kan lọwọ nyin.
11 Nitori lati ilã-õrùn titi o si fi de iwọ̀
rẹ̀ orukọ mi yio tobi lãrin awọn keferi; nibi
gbogbo li a o si fi turàri jona si orukọ mi,
pẹlu ọrẹ mimọ́: nitori orukọ mi o tobi
lãrin awọn keferi, li Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi.
12 Nitori ẹnyin ti sọ ọ di aimọ́, ninu eyi
ti ẹ wipe, Tabili Oluwa di aimọ́; ati eso rẹ̀,
ani onjẹ rẹ̀ ni ohun ẹgan.
13 Ẹnyin wi pẹlu pe, Wo o, agara kili
eyi! ẹnyin ṣitimú si i, li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi; ẹnyin si mu eyi ti o ya, ati arọ,
ati olokunrùn wá; bayi li ẹnyin mu ọrẹ
wá: emi o ha gbà eyi lọwọ nyin? li Oluwa
wi.
14 Ṣugbọn ifibu ni fun ẹlẹtàn na, ti o
ni akọ ninu ọwọ́-ẹran rẹ̀, ti o si ṣe ileri ti o
si fi ohun abùkun rubọ si Oluwa; nitori
Ọba nla li emi, li Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi, ẹru si li orukọ mi lãrin awọn keferi.

## ORI 2.

NJẸ nisisiyi, ẹnyin alufa, ofin yi ni fun
nyin.
2 Bi ẹnyin kì o ba gbọ́, ti ẹnyin kì o ba
fi si aiya, lati fi ogo fun orukọ mi, li Oluwa
awọn omọ-ogun wi; emi o si rán egún si
ori nyin, emi o si fi ibukun nyin ré, lõtọ mo
ti fi ré na, nitori pe, ẹnyin kò fi i si ọkàn.
3 Wò o, emi o ba irugbìn nyin jẹ, emi o
si fi igbẹ́ rẹ́ nyin loju, ani igbẹ́ asè ọ̀wọ
nyin wọnni; a o si kó nyin lọ pẹlu rẹ̀.
4 Ẹnyin o si mọ̀ pe, emi li o ti rán ofin
yi si nyin, ki majẹmu mi le wà pẹlu Lefi,
li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
5 Majẹmu mi ti iyè on alafia wà pẹlu
rẹ̀; mo si fi wọn fun u, nitori bibẹru ti o
bẹru mi, ti ẹru orukọ mi si bà a.
6 Ofin otitọ wà li enu rẹ̀, a kò si ri ìwa-
buburu li etè rẹ̀: o ba mi rìn li alafia ati
ni ododo, o si yi ọ̀pọlọpọ kuro ninu ìwa-
buburu.
7 Nitori ètè alafa iba ma pa ìmọ mọ, ki
nwọn ki o si ma wá ofin li ẹnu rẹ̀: nitori
onṣẹ Oluwa awọn ọmọ-ogun li on iṣe.
8 Ṣugbọn ẹnyin ti yapa kuro li ọ̀na na:
ẹnyin ti mu ọ̀pọlọpọ kọsẹ ninu ofin; ẹnyin
ti ba majẹmu Lefi jẹ, li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi.
9 Nitorina li emi pẹlu ṣe sọ nyin di
ẹgan, ati ẹni aikàsi niwaju gbogbo enia,

Digitized by Google

niwọ̀n bi ẹnyin kò ti pa ọ̀na mi mọ, ti
ẹnyin si ti nṣe ojusaju ninu ofin.
10 Baba kanna ki gbogbo wa ha ni?
Ọlọrun kanna kọ́ ha da wa bi? nitori kili
awa ha ṣe nhùwa arekerekè olukuluku si
arakọnrin rẹ̀, nipa sisọ majẹmu awọn baba
wa di alaimọ́.
11 Juda ti nhùwa arekerekè, a si ti
nhùwa irira ni Israeli ati ni Jerusalemu:
nitori Juda ti sọ ìwa mimọ́ Oluwa di alai-
mọ́, eyi ti o fẹ, o si ti gbe ọmọbirin ọlọrun
ajeji ni iyàwo.
12 Oluwa yio ke ọkọnrin na ti o ṣe eyi
kuro, olukọ ati ẹniti a nkọ, kuro ninu agọ
Jakobu wọnni, ati ẹniti nrubọ ọrẹ si Oluwa
awọn omọ-ogun.
13 Eyi li ẹnyin si tún ṣe, ẹnyin fi omije,
ati ẹkún, ati igbe, bò pẹpẹ Oluwa mọlẹ,
tobẽ ti on kò fi kà ọrẹ nyin si mọ, tabi ki
o fi inu-didùn gbà nkan lọwọ nyin.
14 Ṣugbọn ẹnyin wipe, Nitori kini? Ni-
tori Oluwa ti ṣe ẹlẹri lãrin iwọ ati lãrin
aya ewe rẹ, ẹniti iwọ ti nhùwa ẹ̀tan si:
bẽli ẹgbẹ́ rẹ li on sa iṣe, ati aya majẹmu rẹ.
15 On kò ha ti ṣe ọkan? bẽli on ni iyo-
kù ẹmi. Ẽ si ti ṣe jẹ ọkan? ki on ba le
wá iru-ọmọ bi ti Ọlọrun. Nitorina ẹ tọju
ẹmi nyin, ọ má si jẹ ki ẹnikẹni hùwa ẹ̀tan
si aya ewe rẹ̀.
16 Nitori Oluwa, Ọlọrun Israeli wipe,
on korira ikọ̀silẹ: ẹnikan fi ìwa-ipá bò aṣọ
rẹ̀ mọlẹ, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi: ni-
torina ẹ ṣọ́ ẹmi nyin, ki ẹ má ṣe hùwa ẹ̀tan.
17 Ẹnyin ti fi ọ̀rọ nyin dá Oluwa li
agara. Ṣugbọn ẹnyin wipe, Ninu kini
awa fi da a lagara? Nigbati ẹnyin wipe,
Olukulùku ẹniti o ṣe ibi, rere ni niwaju
Oluwa, inu rẹ̀ si dùn si wọn; tabi, nibo ni
Ọlọrun idajọ gbe wà?

## ORI 3.

KIYESI i, Emi o rán onṣẹ mi, yio si tún
ọ̀na ṣe niwaju mi: ati Oluwa, ti
ẹnyin nwá, yio de li ojijì si tempili rẹ̀, ani
onṣẹ majẹmu na, ti inu nyin dùn si; kiye
si i, o mbọ̀ wá, li Oluwa awọn ọmọ-ogun
wi.
2 Ṣugbọn tali o le gbà ọjọ wíwa rẹ̀? tani
yio si duro nigbati o ba fi ara hàn? nitori
on dabi iná ẹniti ndà fadakà, ati bi ọṣẹ
afọṣọ:
3 On o si joko bi ẹniti nyọ́, ti o si ndà
fadakà: yio si ṣe awọn ọmọ Lefi mọ́ yio
si yọ́ wọn bi wurà on fadakà, ki nwọn ki o
le mu ọrẹ ododo wá fun Oluwa.
4 Nigbana ni ọrẹ Juda ati ti Jerusalemu
yio wù Oluwa, gẹgẹ bi ti ọjọ igbãni, ati
gẹgẹ bi ọdun atijọ.
5 Emi o si sunmọ nyin fun idajọ, emi o
si ṣe ẹlẹri yiyara si awọn oṣó, ati si awọn
panṣaga, ati si awọn abura eké, ati awọn ti
o ni alagbaṣe lara ninu ọyà rẹ̀, ati opo, ati
alainibaba, ati si ẹniti o nrẹ́ alejo jẹ, ti nwọn
kò si bẹ̀ru mi, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
6 Nitori Emi li Oluwa, Emi kò yipada;
nitorina li a kò ṣe run ẹnyin ọmọ Jakobu.
7 Lati ọjọ awọn baba nyin wá li ẹnyin
tilẹ ti yapa kuro ni ilàna mi, ti ẹ kò si pa
wọn mọ. Ẹ yipada si ọdọ mi, Emi o si
yipada si ọdọ nyin, li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi. Ṣugbọn ẹnyin wipe, nipa bawo
li awa o pipada?
8 Enia yio ha jà Ọlọrun li olè? ṣugbọn
ẹnyin sa ti jà mi li olè. Ṣugbọn ẹnyin
wipe, nipa bawo li awa fi jà ọ li olè? Nipa
idamẹwa ati ọrẹ.
9 Riré li a o fi nyin ré: nitori ẹnyin ti
jà mi li olè, ani gbogbo orilẹ-ède yi.
10 Ẹ mu gbogbo idamẹwa wá si ile iṣu-
ra, ki onjẹ ba le wà ni ile mi, ẹ si fi eyi
dán mi wò nisisiyi, bi emi kì yio ba ṣi awọn
ferese ọrun fun nyin, ki nsi tú ibukún jade
fun nyin, tobẽ ti kì yio si aye to lati gbà a.
11 Emi o si ba ajẹnirun wi nitori nyin,
on kì o si run eso ilẹ nyin, bẹ̃ni àjara nyin
kì o rẹ̀ dànu, li Oluwa awọn ọmọ-ọgun wi.
12 Gbogbo orilẹ-ède ni yio si pè nyin li
alabukúnfun: nitori ẹnyin o jẹ ilẹ ti o
wunni, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.
13 Ọ̀rọ nyin ti jẹ lile si mi, li Oluwa
awọn ọmọ-ogun wi. Ṣugbọn ẹnyin wipe,
Ọ̀rọ kili awa sọ si ọ?
14 Ẹnyin ti wipe, Asan ni lati sìn Ọlọ-
run: anfani kili o si wà, ti awa ti pa ilàna
rẹ̀ mọ, ti awa si ti rìn ni igbãwẹ̀ niwaju
Oluwa awọn ọmọ-ogun?
15 Ṣugbọn nisisiyi awa pè agberaga li
alabùkunfun; lõtọ, awọn ti o nhùwa buburu
npọ si i; lõtọ, awọn ti o dán Oluwa wò li
a dá si.
16 Nigbana li awọn ti o bẹ̀ru Oluwa mba
ara wọn sọ̀rọ nigbakugba; Oluwa si tẹti si
i, o si gbọ́, a si kọ iwe-iranti kan niwaju
rẹ̀, fun awọn ti o bẹ̀ru Oluwa, ti nwọn si
nṣe aṣaro orukọ rẹ̀.
17 Nwọn o si jẹ temi ni ini kan, li
Oluwa awọn ọmọ-ọgun wi, li ọjọ na ti emi
o dá; emi o si dá wọn si gẹgẹ bi enia iti
ma dá ọmọ rẹ̀ si ti o nsìn i.
18 Nigbana li ẹnyin o yipada, ẹ o si mọ̀
iyatọ̀ lãrin olododo ati ẹni-buburu, lãrin
ẹniti nsìn Ọlọrun, ati ẹniti kò sìn i.

Digitized by Google

## ORI 4.

SA kiye si i, ọjọ na mbọ̀, ti yio ma jó bi
iná ileru ; ati gbogbo awọn agberaga,
ati gbogbo awọn oluṣe buburu yio dabi
akékù koriko : ọjọ na ti mbọ̀ yio si jo wọn
run, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, ti kì yio
fi kù gbòngbo tabi ẹka fun wọn.
2 Ṣugbọn Õrùn ọdodo yio là, ti on ti
imularada ni iyẹ́-apá rẹ̀, fun ẹnyin ti o bẹ̀ru
orukọ mi ; ẹnyin o si jade lọ, ẹnyin o si
ma dagba bi awọn ẹgbọrọ malu inu agbo.
3 Ẹnyin o si tẹ̀ awọn enia buburu mọlẹ:
nitori nwọn o jasi ẽrú labẹ atẹlẹsẹ̀ nyin, li
ọjọ na ti emi o dá, li Oluwa awọn ọmọ-
ogun wi.
4 Ẹ ranti ofin Mose iranṣẹ mi, eyi ti mo
pa li aṣẹ fun u ni Horebu fun gbogbo Isra-
eli, pẹlu aṣẹ ati idajọ wọnni.
5 Wò o, emi o rán woli Elijah si nyin,
ki ọjọ nla-nlà Oluwa, ati ọjọ ti o li ẹ̀ru to
de :
6 Yio si pa ọkàn awọn baba dà si ti
awọn ọmọ, ati ọkàn awọn ọmọ si ti awọn
baba wọn, ki emi ki o má ba wá fi aiye
gégun.

Digitized by Google

# MAJẸ̀MU TITUN

TI

## JESU KRISTI

# OLUWA ATI OLUGBALA WA.

London:
BRITISH AND FOREIGN BIBLE SOCIETY.
1900

Digitized by Google

Digitized by Google

IHIN RERE TI

# MATTEU.

## ORI 1.

IWE iran Jesu Kristi, ọmọ Dafidi ọmọ
Abrahamu.
2 Abrahamu bí Isaaki; Isaaki si bí
Jakọbu; Jakọbu si bí Juda ati awọn ara-
kọnrin rẹ̀;
3 Juda si bí Faresi ati Sara ti Tamari;
Faresi si bí Esromu; Esromu si bí Aramu;
4 Aramu si bí Aminadabu; Aminadabu
si bí Naaṣoni; Naaṣoni si bí Salmoni;
5 Salmoni si bí Boasi ti Rakabu; Boasi
si bí Obedi ti Rutu: Obedi si bí Jesse;
6 Jesse si bí Dafidi ọba; Dafidi ọba si bí
Solomoni lati ọdọ ẹniti o ti nṣe aya Uria;
7 Solomoni si bí Roboamu; Roboamu
si bí Abia; Abia si bí Asa;
8 Asa si bí Josafati; Josafati si bí Jora-
mu; Joramu si bí Osia;
9 Osia si bí Joatamu; Joatamu si bí
Akasi; Akasi si bí Hesekiah.
10 Hesekiah si bí Manasse; Manasse si
bí Amoni; Amoni si bí Josiah;
11 Josiah si bí Jekoniah ati awọn ara-
kọnrin rẹ̀, li akokò ti a fi kó wọn lọ si
Babiloni.
12 Lẹhin igba ti a fi kó wọn lọ si Babi-
loni ni Jekonia bí Salatieli; Salatieli si bí
Sorobabeli;
13 Sorobabeli si bí Abiudu; Abiudu si
bí Eliakimu; Eliakimu si bí Asoru;
14 Asoru si bí Sadoku; Sadoku si bí
Akimu; Akimu si bí Eliudu;
15 Eliudu si bí Eleasa; Eleasa si bí
Matani; Matani si bí Jakọbu;
16 Jakọbu si bí Josefu ọkọ Maria, lati
ọdọ ẹniti a bí Jesu, ti a npè ni Kristi.
17 Bẹ̃ni gbogbo iran lati Abrahamu wá
de Dafidi jẹ iran mẹrinla; ati lati Dafidi
wá de ikólọ si Babiloni jẹ iran mẹrinla; ati
lati igba ikólọ si Babiloni de igba Kristi o
jẹ iran mẹrinla.
18 ¶ Bi ibí Jesu Kristi ti ri niyi li akokò
ti a fẹ Maria iya rẹ̀ fun Josefu, ki nwọn to
pade, a ri i, o lóyun lati ọwọ́ Ẹmi Mimọ́ wá.
19 Josefu ọkọ rẹ̀, ti iṣe olõtọ enia, ko si
fẹ fi i hàn ni gbangba, o fẹ ikọ̀ ọ silẹ ni
ìkọkọ.
20 Ṣugbọn nigbati o nrò nkan wọnyi,
wò o, angeli Oluwa yọ si i li oju alá, o
wipe, Josefu, iwọ ọmọ Dafidi, má fòya lati
mu Maria aya rẹ si ọdọ; nitori eyi ti o yún
ninu rẹ̀, lati ọwọ́ Ẹmí Mimọ́ ni.
21 Yio si bí ọmọkọnrin kan, Jesu ni iwọ
o pè orukọ rẹ̀: nitori on ni yio gbà awọn
enia rẹ̀ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn.
22 Gbogbo nkan wọnyi si ṣe, ki eyi ti a
ti wi tẹlẹ lati ọdọ Oluwa wá li ẹnu woli nì
ki o le ṣẹ, pe,
23 Kiyesi i, wundia kan yio lóyun, yio
si bí ọmọkọnrin kan, nwọn o ma pè orukọ
rẹ̀ ni Emmanueli, ni itumọ rẹ̀, Ọlọrun wà
pẹlu wa.
24 Nigbati Josefu dide ninu orun rẹ̀, o
ṣe bi angeli Oluwa ti wi fun u, o si mu aya
rẹ̀ si ọdọ:
25 On ko si mọ̀ ọ titi o fi bí akọbi rẹ̀
ọmọkọnrin: o si pè orukọ rẹ̀ ni JESU.

## ORI 2.

NIGBATI a si bí Jesu ni Betlehemu ti
Judea, nigba aiye Herodu ọba, kiyesi
i, awọn amoye kan ti ìha ìla-õrùn wá si
Jerusalemu,
2 Nwọn mbère wipe, Nibo li ẹniti a bí
ti iṣe ọba awọn Ju wà? nitori awa ti ri ira-
wọ rẹ̀ ni ìha ìla-õrùn, awa si wá lati foribalẹ
fun u.
3 Nigbati Herodu ọba si ti gbọ́ nkan
wọnyi, ara rẹ̀ kò lelẹ, ati gbogbo awọn ará
Jerusalemu pẹlu rẹ̀.
4 Nigbati o si pè gbogbo awọn olori alu-
fa ati awọn akọwe enia jọ, o bi wọn lẽre pe,
Nibo li a o gbé bí Kristi.
5 Nwọn si wi fun u pe, Ni Betlehemu ti

Digitized by Google

Judea ni: nitori bẹ̀li a kọwe rẹ̀ lati ọwọ́
woli nì wá,
6 Iwọ Betlehemu ni ilẹ Judea, iwọ ki
iṣe ẹnikekere julọ ninu awọn ọmọ alade
Juda, nitori lati inu rẹ ni Bãlẹ kan yio ti
jade, ti yio jọba Israeli awọn enia mi.
7 Nigbati Herodu pè awọn amoye na si
ìkọkọ, o bi wọn lẹsọlẹsọ li akokò igbati
irawọ na hàn.
8 O si rán wọn lọ si Betlehemu, o wipe,
Ẹ lọ, ẹ wá ọmọ titun na li awari; nigbati
ẹnyin ba si ri i, ẹ pada wá isọ fun mi, ki
emi ki o le wá iforibalẹ fun u pẹlu.
9 Nigbati nwọn si gbọ́ ti ọba, nwọn si
dide; si wò o, irawọ ti nwọn ti ri lati ìha
ìla-õrùn wá, o ṣaju wọn, titi o fi wá iduro
loke ibiti ọmọ titun na gbé wà.
10 Nigbati nwọn si ri irawọ na, nwọn yọ̀
ayọ̀ nlanla.
11 ¶ Nigbati nwọn si wọ̀ ile, nwọn ri
ọmọ titun na pẹlu Maria iya rẹ̀, nwọn wolẹ,
nwọn si foribalẹ fun u: nigbati nwọn ṣi tú
iṣura wọn, nwọn ta a lọrẹ wura, ati turari,
ati ojia.
12 Bi Ọlọrun ti kìlọ fun wọn li oju alá
pe, ki nwọn ki o máṣe pada tọ̀ Herodu lọ
mọ́, nwọn gbà ọ̀na miran lọ si ilu wọn.
13 Nigbati nwọn si ti lọ, kiyesi i, angeli
Oluwa yọ si Josefu li oju alá, o wipe, Dide,
gbé ọmọ titun na pẹlu iya rẹ̀, ki o si sálọ
si Egipti, ki iwọ ki o si gbé ibẹ̀ titi emi o fi
sọ fun ọ; nitori Herodu yio wá ọmọ titún
na lati pa a.
14 Nigbati o si dide, o mu ọmọ titun na
ati iya rẹ̀ li oru, o si lọ si Egipti;
15 O si wà nibẹ̀ titi o fi di igba ikú He-
rodu, ki eyi ti Oluwa wi lati ẹnu woli nì ki
o le ṣẹ, pe, Ni Egipti ni mo ti pè ọmọ mi
jade wá.
16 ¶ Nigbati Herodu ri pe, on di ẹni
ẹ̀tan lọdọ awọn amoye, o binu gidigidi, o
si ranṣẹ, o si pa gbogbo awọn ọmọ ti o wà
ni Betlehemu ati ni ẹkùn rẹ̀, lati awọn ọmọ
ọdún meji mọ abikẹhin wọn, gẹgẹ bi akokò
ti o ti bère lẹsọlẹsọ lọwọ awọn amoye na.
17 Nigbana li eyi ti a ti wi tẹlẹ lati ẹnu
woli Jeremiah wa ṣẹ, pe,
18 Ni Rama ni a gbọ́ ohùn, ohùn-réré,
ati ẹkún, ati ọ̀fọ nla, Rakeli nsọkun awọn
ọmọ rẹ̀, kò gbipẹ, nitoriti nwọn ko si.
19 ¶ Nigbati Herodu si kú, kiyesi i,
angeli Oluwa kan yọ si Josefu li oju alá ni
Egipti;
20 Wipe, Dide, mu ọmọ titun na, ati
iya rẹ̀, ki o si lọ si ilẹ Israeli: nitori awọn
ti nwá ẹmí ọmọ titun na lati pa, ti kú.
21 O si dide, o mu ọmọ titun na ati iya
rẹ̀, o si wá si ilẹ Israeli.
22 Ṣugbọn nigbati o gbọ́ pe Arkelau
jọba ni Judea ni ipò Herodu baba rẹ̀, o bẹ̀ru
lati lọ sibẹ̀; bi Ọlọrun si ti kìlọ fun u li
oju alá, o yipada si apa Galili.
23 Nigbati o si wá, o joko ni ilu kan ti
a npè ni Nasareti: ki eyi ti a ti wi tẹlẹ li
ẹnu woli ki o le ṣẹ, pe, A o pè e ni ará Na-
sareti.

## ORI 3.

NI ijọ wọnni ni Johannu Baptisti wá, o
nwasu ni ijù ti Judea,
2 O si nwipe, Ẹ ronupiwada; nitori
ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ.
3 Nitori eyi li ẹniti woli Isaiah sọ ọ̀rọ rẹ̀,
wipe, Ohùn ẹnikan ti nkigbe ni ijù, Ẹ tún
ọ̀na Oluwa ṣe, ẹ ṣe oju-ọ̀na rẹ̀ tọ́.
4 Johannu na ni irun ibakasiẹ li aṣọ, ati
amure awọ li ẹ̀gbẹ rẹ̀; onjẹ rẹ̀ li eṣú ati
oyin ìgan.
5 Nigbana li awọn ara Jerusalemu, ati
gbogbo awọn ara Judea, ati gbogbo ẹkùn
apa Jordani yiká jade tọ̀ ọ wá,
6 A si baptisi wọn lọdọ rẹ̀ ni odò Jorda-
ni, nwọn njẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn.
7 ¶ Ṣugbọn nigbati o ri ọ̀pọ awọn Farisi
ati Sadusi wá si baptismu rẹ̀, o wi fun wọn
pe, Ẹnyin ọmọ paramọlẹ, tali o kìlọ fun
nyin lati sá kuro ninu ibinu ti mbọ̀?
8 Nitorina, ẹ so eso ti o yẹ fun ironupi-
wada:
9 Ki ẹ má si ṣe rò ninu ara nyin, wipe,
Awa ní Abrahamu ni baba; ki emi wi fun
nyin, Ọlọrun le yọ ọmọ jade lati inu okuta
wọnyi wá fun Abrahamu.
10 Ati pẹlu-pẹlu a ti fi ãke le gbòngbo
igi na; gbogbo igi ti ko ba so eso rere, a o
ke e lùlẹ, a o si wọ́ ọ jú sinu iná.
11 Lõtọ li emi nfi omi baptisi nyin fun
ironupiwada: ṣugbọn ẹnikan ti o pọ̀ju mi
lọ mbọ̀ lẹhin mi, bàta ẹniti emi ko to gbé;
on ni yio fi Ẹmí Mimọ́ ati iná baptisi nyin.
12 Ẹniti atẹ rẹ̀ mbẹ li ọwọ́ rẹ̀, yio si gbá
ile ipaka rẹ̀ mọ́ toto, yio si kó alikama rẹ̀
sinu abà, ṣugbọn ìyangbo ni yio fi iná
ajõku sun.
13 ¶ Nigbana ni Jesu ti Galili wá si
Jordani sọdọ Johannu lati baptisi lọdọ rẹ̀.
14 Ṣugbọn Johannu kọ̀ fun u, wipe,
Emi li a ba baptisi lọdọ rẹ, iwọ si tọ̀ mi wá?
15 Jesu si dahùn, o wi fun u pe, jọwọ
rẹ̀ bẹ̃ na: nitori bẹ̀li o yẹ ti a o fi mu
gbogbo ododo ṣẹ. Bẹ̀li o jọwọ rẹ̀.
16 Nigbati a si baptisi Jesu tan, o jade

Digitized by Google

lẹsẹkanna lati inu omi wá; si wò o, ọrun
ṣí silẹ fun u, Johannu ri Ẹmí Ọlọrun ti
ọrun sọkalẹ bi àdaba, o si bà le ori rẹ̀:
17 Si kiyesi i, ohùn kan lati ọrun wá,
nwipe, Iwọ ni ayanfẹ ọmọ mi, ẹniti inu mi
dùn si gidigidi.

## ORI 4.

NIGBANA li a dari Jesu si ijù lati ọwọ́
Ẹmi lati dán a wò lọwọ Èṣu.
2 Nigbati o si ti gbàwẹ li ogoji ọsán ati
ogoji oru, lẹhinna ni ebi npa a.
3 Nigbati oludanwò de ọdọ rẹ̀, o ni, Bi
iwọ ba iṣe Ọmọ Ọlọrun, paṣẹ ki okuta
wọnyi di akara.
4 Ṣugbọn o dahùn wipe, A ti kọwe rẹ̀ pe,
Enia kò wà nipa akara nikan, bikoṣe nipa
gbogbo ọ̀rọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade wá.
5 Nigbana ni Èṣu gbé e lọ soke si ilu
mimọ́ nì, o gbé e le ṣonṣo oke tempili.
6 O si wi fun u pe, Bi iwọ ba iṣe Ọmọ
Ọlọrun, bẹ́ silẹ fun ara rẹ; A sá ti kọwe rẹ̀
pe, Yio kilọ fun awọn angeli rẹ̀ nitori rẹ, li
ọwọ́ wọn ni nwọn o si gbé ọ soke, ki iwọ ki
o má ba fi ẹsẹ rẹ gbún okuta.
7 Jesu si wi fun u pe; A tún kọ ọ pe,
Iwọ ko gbọdọ dán Oluwa Ọlọrun rẹ wò.
8 Èṣu gbé e lọ si ori òke giga-giga ẹ̀wẹ,
o si fi gbogbo ilẹ ọba aiye ati gbogbo ogo
wọn hàn a;
9 O si wi fun u pe, Gbogbo nkan wọnyi
li emi o fifun ọ, bi iwọ ba wolẹ, ti o si fori-
balẹ fun mi.
10 Nigbana ni Jesu wi fun u pe, Pada
kuro lẹhin mi, Satani, nitori a kọwe rẹ̀ pe,
Oluwa Ọlọrun rẹ ni ki iwọ ki o foribalẹ fun,
on nikanṣoṣo ni ki iwọ ma sìn.
11 Nigbana li Èṣu fi i silẹ lọ, si kiyesi i,
awọn angeli tọ̀ ọ wá, nwọn si nṣe iranṣẹ
fun u.
12 ¶ Nigbati Jesu gbọ́ pe, a fi Johannu
le wọn lọwọ, o dide lọ si Galili;
13 Nigbati o si jade kuro ni Nasareti,
o wá ijoko ni Kapernaumu, eyi ti o mbẹ
leti adagun li ẹkùn Sabuloni ati Neftalimu:
14 Ki eyi ti a wi lati ẹnu woli Isaiah wa
le ṣẹ, pe,
15 Ilẹ Sabuloni ati ilẹ Neftalimu nipa
ọ̀na adagun, li oke Jordani, Galili ti awọn
keferi;
16 Awọn enia ti o joko li òkunkun, ri
imọlẹ nla; ati awọn ti o joko ni ibi iku ati
li ojiji rẹ̀ imọlẹ là fun.
17 ¶ Nigbana ni Jesu bẹ̀rẹ si iwasu o
wipe, Ẹ ronupiwada; nitori ijọba ọrun kù
si dẹ̀dẹ.
18 ¶ Jesu nrìn leti adagun Galili, o ri
awọn arakọnrin meji, Simoni, ẹniti a npè
ni Peteru, ati Anderu arakọnrin rẹ̀, nwọn
nsọ àwọn sinu adagun: nitori nwọn ṣe
apẹja.
19 O si wi fun wọn pe, Ẹ mã tọ̀ mi lẹhin,
emi o si sọ nyin di apẹja enia.
20 Nwọn si fi àwọn wọn silẹ lojukanna,
nwọn si ntọ̀ ọ lẹhin.
21 Bi o si ti nlọ siwaju ibẹ̀, o ri awọn
arakọnrin meji, Jakọbu ọmọ Sebede, ati
Johannu arakọnrin rẹ̀, ninu ọkọ̀ pẹlu Sebede
baba wọn, nwọn ndí àwọn wọn; o si pè
wọn.
22 Lojukanna nwọn si fi ọkọ̀ ati baba
wọn silẹ, nwọn si ntọ̀ ọ lẹhin.
23 Jesu si rìn ni gbogbo ẹkùn Galili, o
nkọni ni sinagogu wọn, o si nwasu ihin-
rere ijọba, o si nṣe awotan gbogbo aisan ati
gbogbo arunkarun li ara awọn enia.
24 Okikí rẹ̀ si kàn yi gbogbo Siria ká;
nwọn si ngbé awọn olokunrun ti o li arun-
karun wá sọdọ rẹ̀, ati awọn onirora, ati
awọn ti o li ẹmi èṣu, ati gbogbo awọn ti o
o nsinwin, ati awọn ti o li ẹ̀gba; o si ṣe
awotan gbogbo wọn.
25 Ọ̀pọlọpọ enia si tọ̀ ọ lẹhin lati Galili,
ati Dekapoli, ati Jerusalemu, ati lati Judea
wá, ati lati oke odò Jordan.

## ORI 5.

NIGBATI o si ri ọ̀pọ enia, o gùn ori òke
lọ: nigbati o si joko, awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀ tọ̀ ọ wá.
2 O si yà ẹnu rẹ̀, o si kọ́ wọn, wipe,
3 Alabukún-fun li awọn òtoṣi li ẹmí:
nitori ti wọn ni ijọba ọrun.
4 Alabukún-fun li awọn ẹniti nkãnu:
nitoriti a o tù wọn ninu.
5 Alabukún-fun li awọn ọlọkàn tutù:
nitori nwọn o jogún aiye.
6 Alabukún-fun li awọn ẹniti ebi npa
ati ti ongbẹ ngbẹ sipa ododo: nitori a o fi
kún wọn.
7 Alabukún-fun li awọn alãnu: nitori
nwọn o ri ãnu gbà.
8 Alabukún-fun li awọn oninu funfun:
nitori nwọn o ri Ọlọrun.
9 Alabukún-fun li awọn onilaja: nitori
awọn ọmọ Ọlọrun ni a o ma pè wọn.
10 Alabukún-fun li awọn ẹniti a nṣe
inunibini si nitori ododo: nitori ti wọn ni
ijọba ọrun.
11 Alabukún-fun li ẹnyin, nigbati nwọn
ba nkẹgan nyin, ti nwọn ba nṣe inunibini

Digitized by Google

si nyin, ti nwọn ba nfi eke sọ̀rọ buburu gbogbo si nyin nitori emi.

12 Ẹ ma yọ̀, ki ẹnyin ki o si ma yọ̀ ayọ̀ nla: nitori ère nyin pọ̀ li ọrun: bẽ̩ni nwọn sá ṣe inunibini si awọn wolĩ ti o ti mbẹ ṣaju nyin.

13 ¶ Ẹnyin ni iyọ̀ aiye: ṣugbọn bi iyọ̀ ba di obu, nibo li a o gbé fi i dùn? nigbana li o di asan, bikoṣepe ki a gbá a danù, ki o si di itẹmọlẹ li atẹlẹsẹ enia.

14 Ẹnyin ni imọlẹ aiye. Ilu ti a tẹ̀ lori òke ko le fi ara sin.

15 Bẽ̩ni ko si ẹniti itàn fitila tan, ti ifi i sabẹ òṣuwọn; bikoṣe lori ọpá fitila, a si fi imọlẹ fun gbogbo ẹniti mbẹ ninu ile.

16 Ẹ jẹ ki imọlẹ nyin ki o mọlẹ tobẽ̩ niwaju enia, ki nwọn ki o le ma ri iṣẹ rere nyin, ki nwọn ki o le ma yìn Baba nyin ti mbẹ li ọrun logo.

17 ¶ Ẹ máṣe rò pe, emi wá lati pa ofin tabi wolĩ run: emi kò wá lati parun, bikoṣe lati mu ṣẹ.

18 Lõtọ ni mo sá wi fun nyin, Titi ọrun on aiye yio fi kọja lọ, kikini ọ̀rọ ninu ofin kì yio kọja, bi o ti wù ki o ri, titi gbogbo rẹ̀ yio fi ṣẹ.

19 Ẹnikẹni ti o ba rú ọkan kikini ninu ofin wọnyi, ti o ba si nkọ́ awọn enia bẽ̩, on na li a o pè ni kikini ni ijọba ọrun: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba nṣe wọn ti o ba si nkọ́ wọn, on na li a o ma pè ni ẹni-nla ni ijọba ọrun.

20 Nitori mo wi fun nyin, bikoṣepe ododo nyin ba kọja ododo awọn akọwe ati ti awọn Farisi, ẹnyin kì yio le de ijọba ọrun bi o ti wù ki o ri.

21 ¶ Ẹnyin ti gbọ́ bi a ti wi fun awọn ará igbãni pe, Iwọ kò gbọdọ pania; ẹnikẹni ti o ba pania yio wà li ewu idajọ.

22 Ṣugbọn emi wi fun nyin, ẹnikẹni ti o binu si arakọnrin rẹ̀ lasan, yio wà li ewu idajọ; ati ẹnikẹni ti o ba wi fun arakọnrin rẹ̀ pe, Raka, yio wà li ewu ajọ awọn igbimọ; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba wipe, Iwọ aṣiwere, yio wà li ewu iná ajõku ọrun apadi.

23 Nitorina bi iwọ ba nmu ẹ̀bun rẹ wá si ibi pẹpẹ, bi iwọ ba ranti pe, arakọnrin rẹ li ohun kan ninu si ọ:

24 Fi ẹ̀bun rẹ silẹ nibẹ̀ niwaju pẹpẹ, pada lọ sile; tète ba arakọnrin rẹ làja na, nigbana ni ki o to wá ibùn ẹ̀bun rẹ.

25 Ba ọtà rẹ rẹ́ kánkan, nigbati iwọ wà li ọ̀na pẹlu rẹ̀; ki ọtá rẹ ki o má ba fi ọ le onidajọ lọwọ, onidajọ a si fi ọ le tẽtu lọwọ, a si gbè ọ sọ sinu tubu.

26 Lõtọ ni mo wi fun ọ, Iwọ kì yio jade kuro nibẹ̀, titi iwọ o fi san owo kan iyokù.

27 ¶ Ẹnyin ti gbọ́ bi a ti wi fun awọn ará igbãni pe, Iwọ ko gbọdọ ṣe panṣaga.

28 Ṣugbọn emi wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba wò obirin kan ti o ba nṣe ifẹkufẹ si i, o ti bá a ṣe panṣaga tan li ọkàn rẹ̀.

29 Bi oju ọtún rẹ ba mu ọ kọsẹ̀, yọ ọ jade, ki o si mu u kuro lara rẹ; o sá li ère fun ọ, ki ẹ̀ya ara rẹ kan ki o ṣegbé, jù ki a wọ́ gbogbo ara rẹ jù sinu iná ọrun apadi lọ.

30 Bi ọwọ́ ọtún rẹ ba mu ọ kọsẹ̀, ke e kuro, ki o si mu u kuro lara rẹ; o sá li ère fun ọ, ki ẹ̀ya ara rẹ kan ki o ṣegbé, jù ki a wọ́ gbogbo ara rẹ jù sinu iná ọrun apadi lọ.

31 A ti wi pẹlu pe, ẹnikẹni ti o ba kọ̀ aya rẹ̀ silẹ, jẹ ki o fi iwe ikọsilẹ le e lọwọ.

32 Ṣugbọn emi wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba kọ̀ aya rẹ̀ silẹ, bikoṣe nitori àgbere, o mu u ṣe panṣaga; ẹnikẹni ti o ba si gbé ẹniti a kọ̀ silẹ ni iyawo, o ṣe panṣaga.

33 ¶ Ẹnyin ti gbọ́ ẹ̀wẹ bi a ti wi fun awọn ará igbãni pe, Iwọ kò gbọdọ fi ibura ṣe ileri, bikoṣepe ki iwọ ki o si mu ileri ibura rẹ ṣẹ fun Oluwa.

34 Ṣugbọn emi wi fun nyin Ẹ máṣe bura rára; iba ṣe ifi ọrun bu, nitoripe itẹ́ Ọlọrun ni.

35 Tabi ifi aiye bu, nitori apoti itisẹ rẹ̀ ni; tabi ifi Jerusalemu bu, nitori ilu ọba nla ni.

36 Bẽ̩ni iwọ kò gbọdọ fi ori rẹ bura, nitori iwọ ko le sọ irun kan di funfun tabi dudu.

37 Ṣugbọn jẹ ki gbogbo ọ̀rọ nyin jẹ, Bẽ̩ni, bẽ̩ni; Bẽ̩kọ, bẽ̩kọ; nitoripe ohunkohun ti o ba jù wọnyi lọ, nipa ibi li o ti wa.

38 ¶ Ẹnyin ti gbọ́ bi a ti wi pe, Oju fun oju, ati ehín fun ehín:

39 Ṣugbọn emi wi fun nyin, Ẹ má kọ̀ ibi; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba gbá ọ li ẹrẹkẹ ọtún, yi ti òsi si i pẹlu.

40 Bi ẹnikan ba sùn ọ ni ile ẹjọ, ti o si gbà ọ li ẹ̀wu lọ, jẹ ki o gbà agbáda rẹ pẹlu.

41 Ẹnikẹni ti o ba fi agbara mu ọ lọ si mile kan, bá a de meji.

42 Fifun ẹniti o bère lọwọ rẹ; ati lọdọ ẹniti o nfẹ win lọwọ rẹ, máṣe dù u.

43 ¶ Ẹnyin ti gbọ́ bi a ti wipe, Ki iwọ fẹ ọmọnikeji rẹ, ki iwọ si korira ọtá rẹ.

44 Ṣugbọn emi wi fun nyin, Ẹ fẹ awọn ọtá nyin, sure fun awọn ẹniti o nfi nyin ré, ṣore fun awọn ti o korira nyin, ki ẹ si gbà

Digitized by Google

adura fun awọn ti nfi arankàn lò nyin, ti
nwọn nṣe inunibini si nyin ;
45 Ki ẹnyin ki o le ma ṣe ọmọ Baba
nyin ti mbẹ li ọrun : nitoriti o mu õrùn
ràn sara enia buburu ati sara enia rere, o
rọ̀jo fun awọn olõtọ ati fun awọn alaiṣõtọ.
46 Njẹ bi ẹnyin ba fẹ awọn ti o fẹ nyin,
ọpẹ́ kili ẹnyin ni ? bẹ̃ gẹgẹ ki awọn agbo-
wode nṣe ?
47 Bi ẹnyin si nkí kìki awọn arakọnrin
nyin, kili ẹ ṣe jù awọn ẹlomiran lọ ? bẹ̃
gẹgẹ ki awọn agbowode nṣe ?
48 Nitorina ki ẹnyin ki o pé, bi Baba
nyin ti mbẹ li ọrun ti pé.

## ORI 6.

EKIYESI ara ki ẹ máṣe itọrẹ ãnu nyin
niwaju enia, ki a ba le ri nyin : bi
o ba ri bẹ̃ ẹnyin ko li ère lọdọ Baba nyin
ti mbẹ li ọrun.
2 Nitorina nigbati iwọ ba nṣe itọrẹ ãnu
rẹ, máṣe fun fère niwaju rẹ, bi awọn aga-
bagebe ti nṣe ni sinagogu ati ni ita, ki
nwọn ki o le gbà iyìn enia. Lõtọ ni mo
wi fun nyin, nwọn ti gbà ère wọn na.
3 Ṣugbọn nigbati iwọ ba nṣe itọrẹ ãnu
rẹ, máṣe jẹ ki ọwọ́ òsi rẹ ki o mọ̀ ohun ti
ọwọ́ ọtún rẹ nṣe ;
4 Ki itọrẹ ãnu rẹ ki o le wà ni ìkọkọ ;
Baba rẹ ti o si riran ni ìkọkọ, on tikararẹ̀
yio san a fun ọ ni gbangba.
5 ¶ Nigbati iwọ ba ngbadura, máṣe dabi
awọn agabagebe ; nitori nwọn fẹ ati ma
duro gbadura ni sinagogu ati ni igun ọ̀na
ita, ki enia ki o ba le ri wọn. Lõtọ ni mo
wi fun nyin, nwọn ti jẹ ère wọn na.
6 Ṣugbọn iwọ nigbati iwọ ba ngbadura,
wọ̀ iyẹwu rẹ lọ, nigbati iwọ ba si sé ilẹkùn
rẹ tan, gbadura si Baba rẹ ti mbẹ ni ìkọ-
kọ ; Baba rẹ ti o si riran ni ìkọkọ yio san
a fun ọ ni gbangba.
7 Ṣugbọn nigbati ẹnyin ba ngbadura, ẹ
máṣe atunwi asan bi awọn keferi ; nwọn
ṣebi a o ti itori ọ̀rọ pipọ gbọ́ ti wọn.
8 Nitorina ki ẹnyin máṣe dabi wọn :
Baba nyin sá mọ̀ ohun ti ẹnyin ṣe alaini,
ki ẹ to bère lọwọ rẹ̀.
9 Nitorina bayi ni ki ẹnyin ma gbadura :
Baba wa ti mbẹ li ọrun ; Jẹ ki a bọ̀wọ fun
orukọ rẹ.
10 Ki ijọba rẹ de ; Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, bi
ti ọrun, bẹ̃ni li aiye.
11 Fun wa li onjẹ õjọ wa loni.
12 Dari gbese wa jì wa, bi awa ti ndarijì
awọn onigbese wa.
13 Má si fà wa sinu idẹwò, ṣugbọn gbà
wa ninu tulasin. Nitori ijọba ni tirẹ, ati
agbara, ati ogo, lailai. Amin.
14 Nitori bi ẹnyin ba fi ẹ̀ṣẹ awọn enia jì
wọn, Baba nyin ti mbẹ li ọrun yio fi ẹ̀ṣẹ ti
nyin jì nyin.
15 Ṣugbọn bi ẹnyin ko ba fi ẹ̀ṣẹ awọn
enia jì wọn, Baba nyin ti mbẹ li ọrun kì
yio si fi ẹ̀ṣẹ ti nyin jì nyin.
16 ¶ Ati pẹlu nigbati ẹnyin ba ngbàwẹ,
ẹ máṣe dabi awọn agabagebe ni oloju fifaro ;
nwọn a ba oju jẹ, ki nwọn ki o ba le fi ara
hàn fun enia pe nwọn ngbàwẹ. Lõtọ ni
mo wi fun nyin, Nwọn ti gbà ère wọn na.
17 Ṣugbọn iwọ, nigbati iwọ ba ngbàwẹ,
fi oróro kùn ori rẹ, ki o si bọju rẹ ;
18 Ki iwọ ki o máṣe fi ara hàn fun enia
pe iwọ ngbàwẹ, bikoṣe fun Baba rẹ ti o
mbẹ ni ìkọkọ ; Baba rẹ ti o si riran ni
ìkọkọ yio san a fun ọ ni gbangba.
19 ¶ Ẹ máṣe tò iṣura jọ fun ara nyin li
aiye, nibiti kòkoro ati ipara iba a jẹ, ati
nibiti awọn olè irunlẹ ti nwọn si ijale.
20 Ṣugbọn ẹ tò iṣura jọ fun ara nyin li
ọrun, nibiti kòkoro ati ipara ko le ba a jẹ,
ati nibiti awọn olè kò le runlẹ ki wọn si
jale.
21 Nitori nibiti iṣura nyin gbé wà, nibẹ̀
li ọkàn nyin yio gbé wà pẹlu.
22 Oju ni imọlẹ ara : nitorina bi oju rẹ
ba mọ́, gbogbo ara rẹ ni yio jẹ kìki imọlẹ.
23 Ṣugbọn bi oju rẹ ba buru, gbogbo ara
rẹ ni yio ṣú fun òkunkun. Njẹ bi imọlẹ ti
mbẹ ninu rẹ ba di òkunkun, òkunkun na
yio ti tobi to !
24 ¶ Kò si ẹniti o le sìn oluwa meji :
bikoṣepe o korira ọkan, ki o si fẹ ekeji ; bi
ko si ṣe bẹ̃ yio faramọ ọkan, yio si yàn
ekeji ni ipọsi. Ẹnyin ko le sìn Oluwa pẹlu
mamoni.
25 Nitorina mo wi fun nyin, Ẹ máṣe ṣe
aniyan nitori ẹmí nyin pe, kili ẹ o jẹ, tabi
kili ẹ o mu ; ati fun ara nyin pe, kili ẹ o
fi bora. Ẹmí ko jù onjẹ lọ ? tabi ara ni kò
jù aṣọ lọ ?
26 Ẹ sá wò ẹiyẹ oju ọrun ; nwọn kì
ifunrugbin, bẹ̃ni nwọn kì iká, nwọn kì isi
ikójọ sinu abà, ṣugbọn Baba nyin ti mbẹ li
ọrun mbọ́ wọn. Ẹnyin kò ha sian jù wọn
lọ ?
27 Tani ninu nyin nipa aniyàn ṣiṣe ti o
le fi igbọnwọ kan kún ọjọ aiyé rẹ̀ ?
28 Ẽṣe ti ẹnyin sì fi nṣe aniyan nitori
aṣọ ? Kiyesi lili ti mbẹ ni igbẹ́ bi nwọn ti
ndàgba ; nwọn kì iṣiṣẹ, bẹ̃ni nwọn kì
irànwu :
29 Mo si wi fun nyin pe, a ko ṣe Solo-

Digitized by Google

moni pāpā li ọsọ ninu gbogbo ogo rẹ̀ to bi
ọkan ninu wọnyi.
30 Njẹ bi Ọlọrun ba wọ̀ korikọ igbẹ́ li
aṣọ tobẹ̃ ti o wà loni, ti a si gbá a sinu iná
lọla, melomelo ni ki yio fi le wọ̀ nyin li aṣọ,
ẹnyin oni-kekere igbagbọ?
31 Nitorina ẹ má gbèro, wipe, Kili a o
jẹ? tabi, kili a o mu? tabi, nibo li a o ti fi
aṣọ wọ̀ wa?
32 Nitori gbogbo nkan wọnyi li awọn
keferi nwá kiri. Baba nyin ti mbẹ li ọrun
mọ̀ pe, ẹnyin ko le ṣe alaini gbogbo nkan
wọnyi.
33 Ṣugbọn ẹ tète ma wá ijọba Ọlọrun
na, ati ododo rẹ̀; gbogbo nkan wọnyi li a
o si fi kún u fun nyin.
34 Nitorina ẹ máṣe ṣe aniyan nitori ọla;
ọla ni yio ṣe aniyan ohun ara rẹ̀. Buburu
ti õjọ to fun u.

## ORI 7.

EMÁṢE dani li ẹjọ, a kì yio si da nyin li
ẹjọ.
2 Irú idajọ ti ẹnyin ba ṣe, on ni a o si
ṣe fun nyin; irú òṣuwọn ti ẹnyin ba fi
wọ̀n, on li a o si fi wọ̀n fun nyin.
3 Etiṣe ti iwọ si nwò ẹrún igi ti mbẹ li
oju arakọnrin rẹ, ṣugbọn iwọ ko kiyesi ìti
igi ti mbẹ li oju ara rẹ?
4 Tabi iwọ o ti ṣe wi fun arakọnrin rẹ
pe, Jẹ ki emi yọ ẹrún igi ti mbẹ li oju rẹ,
si wò o, ìti igi li oju iwọ tikararẹ.
5 Iwọ agabagebe, tètekọ́ yọ ìti igi jade
kuro li oju ara rẹ na, nigbana ni iwọ o si
to riran gbangba lati yọ ẹrún igi kuro ti
mbẹ li oju arakọnrin rẹ.
6 ¶ Ẹ máṣe fi ohun mimọ́ fun ajá, ki ẹ
má si ṣe sọ perli nyin siwaju ẹlẹdẹ, ki
nwọn má ba fi ẹsẹ tẹ̀ wọn mọlẹ, nwọn o si
yipada ẹ̀wẹ, nwọn a si bù nyin ṣán.
7 ¶ Bère, a o si fifun nyin; wá kiri,
ẹnyin o si ri; kànkun, a o si ṣí i silẹ fun
nyin.
8 Nitori ẹnikẹni ti o bère o ri gbà; ẹniti
o wá kiri o ri: ati fun ẹniti o kànkun, a o
ṣí i silẹ.
9 Tabi ọkọnrin wo ni ti mbẹ ninu nyin,
bi ọmọ rẹ̀ bère akara, ti o jẹ fi okuta fun u?
10 Tabi bi o bère ẹja, ti o jẹ fun u li
ejò?
11 Njẹ bi ẹnyin ti iṣe enia buburu, ba
mọ̀ bi ã ti fi ẹ̀bun rere fun awọn ọmọ nyin,
melomelo ni Baba nyin ti mbẹ li ọrun yio
fi ohun rere fun awọn ti o bère lọwọ rẹ̀?
12 Nitorina gbogbo ohunkohun ti ẹnyin
ba nfẹ ki enia ki o ṣe si nyin, bẹ̃ni ki ẹnyin
ki o si ṣe si wọn gẹgẹ; nitori eyi li ofin ati
awọn woli.
13 ¶ Ẹ ba ẹnu-ọ̀na hihá wọle; gbòro li
ẹnu-ọ̀na na, ati onibú li oju-ọ̀na na ti o lọ
si ibi iparun; ọ̀pọlọpọ li awọn ẹniti nrìn
nibẹ̀.
14 Nitori bi hihá ti ni ẹnu-ọ̀na na, ati
toro li oju-ọ̀na na, ti o lọ si ibi ìye, diẹ li
awọn ẹniti o nrìn i.
15 ¶ Ẹ ma kiyesi awọn eke woli ti o ntọ̀
nyin wá li awọ agutan, ṣugbọn apanijẹ
ikõkò ni nwọn ninu.
16 Eso wọn li ẹnyin o fi mọ̀ wọn. Enia
ama ká eso ajara lori ẹgún ọgàn, tabi ama
ká eso ọpọtọ ninu ẹ̀wọn?
17 Gẹgẹ bẹ̃ gbogbo igi rere ni iso eso
rere; ṣugbọn igi buburu ni iso eso buburu.
18 Igi rere ko le so eso buburu, bẹ̃ni igi
buburu ko si le so eso rere.
19 Gbogbo igi ti ko ba so eso rere, a ké
e lùlẹ, a si wọ́ ọ sọ sinu iná.
20 Nitorina nipa eso wọn li ẹnyin o fi
mọ̀ wọn.
21 ¶ Ki iṣe gbogbo ẹniti npè mi li
Oluwa, Oluwa, ni yio wọle ijọba ọrun; bi-
kọṣe ẹniti nṣe ifẹ ti Baba mi ti mbẹ li
ọrun.
22 Ọpọlọpọ enia ni yio wi fun mi li ọjọ
na pe, Oluwa, Oluwa, awa ko ha sọtẹlẹ li
orukọ rẹ? ati orukọ rẹ ki a fi lé awọn ẹmi
èṣu jade? ati li orukọ rẹ ki a fi ṣe ọ̀pọ iṣẹ
iyanu nla?
23 Nigbana li emi o si jẹwọ wi fun wọn
pe, Emi kò mọ̀ nyin ri, ẹ kuro lọdọ mi,
ẹnyin oniṣẹ ẹ̀ṣẹ.
24 ¶ Nitorina ẹnikẹni ti o ba gbọ́ ọ̀rọ
temi wọnyi, ti o ba si ṣe wọn, emi o si fi wé
ọlọ́gbọn enia kan, ti o kọ́ ile rẹ̀ si ori àpata:
25 Nigbati òjo rọ̀, ikún omi de, afẹfẹ fẹ́,
nwọn bilù ile na, ko le ṣubu, nitoriti a fi
ipilẹ rẹ̀ sọlẹ lori àpata.
26 Ẹnikẹni ti o ba si gbọ́ ọ̀rọ temi wọnyi,
ti kò si ṣe wọn, on li emi o fi wé aṣiwere
enia kan ti o kọ́ ile rẹ̀ si ori iyanrin:
27 Nigbati òjo rọ̀, ti ikún omi de, ti
afẹfẹ si fẹ́, nwọn si bilù ile na, o si wó;
iwó rẹ̀ si pọ̀ jọjọ.
28 Nigbati o si ṣe ti Jesu pari gbogbo
ọ̀rọ wọnyi tan, ẹnu yà gbogbo enia si ẹkọ́
rẹ̀:
29 Nitori o kọ́ wọn bi ẹniti o li ọlá, kò
si dabi awọn akọwe.

## ORI 8.

NIGBATI o ti ori òke sọkalẹ, ọ̀pọ enia
ntọ̀ ọ lẹhin.

Digitized by Google

2 Si wò o, adẹtẹ̀ kan wá, o ntẹriba fun u, o wipe, Oluwa, bi iwọ ba fẹ, iwọ le sọ mi di mimọ́.

3 Jesu si nà ọwọ́ rẹ̀, o fi bà a, o wipe, Mo fẹ; iwọ di mimọ́. Lojukanna ẹ̀tẹ rẹ̀ si mọ́.

4 Jesu si wi fun u pe, Wò o, máṣe sọ fun ẹnikan; ṣugbọn ma ba ọ̀na rẹ lọ, fi ara rẹ hàn fun awọn alufa, ki o si bun ẹ̀bun rẹ niti ẹrí fun wọn, bi Mose ti sọ ọ li ofin.

5 ¶ Nigbati Jesu si wọ̀ Kapernaumu, balogun ọrún kan tọ̀ ọ wá, o mbẹ̀ ẹ,

6 O si nwipe, Oluwa, ọmọ-ọdọ mi dubulẹ arùn ẹ̀gba ni ile, ni irora pupọ̀.

7 Jesu si wi fun u pe, emi mbọ̀ wá mu u lara da.

8 Balogun ọrún na dahùn, o si wipe, Oluwa, emi ko yẹ ti iwọ iba fi wọ̀ abẹ orule mi; ṣugbọn sọ kìki ọ̀rọ kan, a o si mu ọmọ-ọdọ mi lara da.

9 Ẹniti o wà labẹ oyè sá li emi, emi si li ọmọ-ogun lẹhin mi; mo wi fun ẹnikan pe, Lọ, a si lọ; ati fun ẹnikeji pe, Wá, a si wá; ati fun ọmọ-ọdọ mi pe, Ṣe eyi, a si ṣe e.

10 Nigbati Jesu gbọ́, ẹnu yà a, o si wi fun awọn ti o ntọ̀ ọ lẹhin pe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, emi ko ri igbagbọ́ nla bi irú eyi ninu awọn enia Israeli.

11 Mo si wi fun nyin, ọ̀pọlọpọ enia ni yio ti ìha ìla-õrùn ati ìha ìwọ-õrùn wá, nwọn o si ba Abrahamu, ati Isaaki, ati Jakọbu joko ni ijọba ọrun.

12 Ṣugbọn awọn ọmọ ijọba li a o sọ sinu òkunkun biribiri ọ̀hun, nibẹ̀ ni nwọn o ma sọkun, ti nwọn o si ma pa ehin keke.

13 Jesu si wi fun balogun ọrún na pe, Ma ba ọ̀na tirẹ lọ, bi iwọ si ti gbagbọ́, bẽni ki o ri fun ọ. A si mu ọmọ-ọdọ rẹ̀ lara da ni wakati kanna.

14 ¶ Nigbati Jesu si wọ̀ ile Peteru lọ, o ri iya aya rẹ̀ ni ibubulẹ, o nrun ibà.

15 O si fi ọwọ́ bà a li ọwọ́, ibà si fi i silẹ; on si dide, o si ṣe iranṣẹ fun wọn.

16 ¶ Nigbati o si di aṣalẹ, nwọn mu ọ̀pọlọpọ awọn ẹniti o ni ẹmi èṣu wá sọdọ rẹ̀: o si fi ọ̀rọ rẹ̀ lé awọn ẹmi na jade, o si mu awọn olokunrun lara da.

17 Ki eyi ti a ti sọ lati ẹnu woli Isaiah wá le ṣẹ, pe, On tikararẹ̀ gbà ailera wa, o si nrù arùn wa.

18 ¶ Nigbati Jesu ri ọ̀pọlọpọ enia lọdọ rẹ̀, o paṣẹ fun wọn lati lọ si apa keji adagun.

19 Akọwe kan si tọ̀ ọ wá, o wi fun u pe, Olukọni, emi o ma tọ̀ ọ lẹhin nibikibi ti iwọ nlọ.

20 Jesu si wi fun u pe, Awọn kọ̀lọkọlọ ni ihò, ati awọn ẹiyẹ oju ọrun ni itẹ́; ṣugbọn Ọmọ enia kò ni ibi ti yio gbé fi ori rẹ̀ le.

21 Ekeji ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si wi fun u pe, Oluwa, jẹ ki emi ki o kọ́ lọ isinkú baba mi na.

22 Ṣugbọn Jesu wi fun u pe, Iwọ ma tọ̀ mi lẹhin, jẹ ki awọn okú ki o ma sin okú wọn.

23 ¶ Nigbati o si bọ si ọkọ̀, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ tẹ̀le e.

24 Si wò o, afẹfẹ nla dide ninu adagun tobẽ ti a fi bò ọkọ̀ mọlẹ ninu riru omi; ṣugbọn on sùn.

25 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ tọ̀ ọ wá, nwọn jí i, nwọn wipe, Oluwa, gbà wa là, awa gbé.

26 O si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi ṣe ojo bẹ̃, ẹnyin onigbagbọ́ kekere? Nigbana li o dide, o si ba afẹfẹ ati adagun wi; idakẹrọrọ si de.

27 Ṣugbọn ẹnu yà awọn ọkọnrin na, nwọn wipe, Irú ọkọnrin kili eyi, ti afẹfẹ ati omi adagun gbà ti rẹ̀ gbọ́?

28 ¶ Nigbati o si de apa keji ni ilẹ awọn ara Gergesene, awọn ọkọnrin meji ẹlẹmi èṣu pade rẹ̀, nwọn nti inu ibojì jade wá, nwọn rorò gidigidi tobẽ ti ẹnikan ko le kọja li ọ̀na ibẹ̀.

29 Si wò o, nwọn kigbe soke wipe, Kini ṣe tawa tirẹ, Jesu, iwọ Ọmọ Ọlọrun? iwọ wá lati da wa loro ki o to to akokò?

30 Agbo ọ̀pọ ẹlẹdẹ ti njẹ mbẹ li ọ̀na jijìn si wọn.

31 Awọn ẹmi èṣu na si bẹ̀ ẹ, wipe, Bi iwọ ba lé wa jade, jẹ ki awa ki o lọ sinu agbo ẹlẹdẹ yi.

32 O si wi fun wọn pe, Ẹ ma lọ. Nigbati nwọn si jade, nwọn lọ sinu agbo ẹlẹdẹ na; si wò o, li agbara ni gbogbo agbo ẹlẹdẹ na sure lọ li ogedengbe sinu adagun, nwọn si ṣegbé ninu omi.

33 Awọn ẹniti nṣọ wọn si sá, nwọn si mu ọ̀na wọn pọ̀n lọ si ilu, nwọn ròhin ohun gbogbo, ati ohun ti a ṣe fun awọn ẹlẹmi èṣu.

34 Si wò o, gbogbo ará ilu na si jade wá ipade Jesu; nigbati nwọn si ri i, nwọn bẹ̀ ẹ, ki o le lọ kuro li àgbegbe wọn.

## ORI 9.

O SI bọ sinu ọkọ̀, o rekọja, o si wá si ilu on tikararẹ̀.

2 Si kiyesi i, nwọn gbé ọkọnrin kan ti o li ẹ̀gba wá sọdọ rẹ̀, o dubulẹ lori akete; nigbati Jesu ri igbagbọ́ wọn, o wi fun ẹlẹ-

gba pe, Ọmọkọnrin, tújuka, a dari ẹ̀ṣẹ rẹ
jì ọ.
3 Si kiyesi i, awọn ọkan ninu awọn
akọwe nwi ninu ara wọn pe, Ọkọnrin yi
nsọ ọ̀rọ buburu.
4 Jesu si mọ̀ ìro inu wọn, o wipe, Nitori
kili ẹnyin ṣe nrò buburu ninu nyin ?
5 Ewo li o yajù lati wi, yala a dari ẹ̀ṣẹ
rẹ jì ọ ; tabi lati wipe, Dide, ki o si ma
rìn ?
6 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe, Ọmọ
enia li agbara li aiye lati dari ẹ̀ṣẹ jìni, (o si
wi fun alarun ẹ̀gba na pe,) Dide, si gbé
akete rẹ, ki o si ma lọ ile rẹ.
7 O si dide, o lọ si ile rẹ̀.
8 Nigbati ijọ enia si ri i, ẹnu yà wọn,
nwọn yìn Ọlọrun logo, ti o fi irú agbara
bayi fun enia.
9 ¶ Bi Jesu si ti nrekọja lati ibẹ̀ lọ, o ri
ọkọnrin kan ti a npè ni Matteu, o joko ni
bode ; o wi fun u pe, Mã tọ̀ mi lẹhin. O
si dide, o tọ̀ ọ lẹhin.
10 ¶ O si ṣe, bi Jesu ti joko tì onjẹ, si
kiyesi i, ọ̀pọ awọn agbowode ati ẹlẹṣẹ wá,
nwọn si ba a joko pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀.
11 Nigbati awọn Farisi si ri i, nwọn wi
fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe, Ẽṣe ti Olukọ
nyin fi mba awọn agbowode ati awọn ẹlẹṣẹ
jẹun pọ̀ ?
12 Ṣugbọn nigbati Jesu gbọ́, o wi fun
wọn pe, Awọn ti ara wọn le, kò wá oniṣe-
gun, bikoṣe awọn ti ara wọn kò da.
13 Ṣugbọn ẹ lọ, ẹ si kọ́ bi ã ti mọ̀ eyi si,
Anu li emi o gbà, kì iṣe ẹbọ : Nitori emi
kò wá lati pè awọn olododo, bikoṣe awọn
ẹlẹṣẹ si ironupiwada.
14 ¶ Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin Jo-
hannu tọ̀ ọ wá, wipe Ẽṣe ti awa ati awọn
Farisi fi ngbàwẹ nigbagbogbo, ṣugbọn
awọn ọmọ-ẹhin rẹ ko gbàwẹ ?
15 Jesu si wi fun wọn pe, Ẹnyin le mu
ki awọn ọmọ ile iyawo gbàwẹ, nigbati ọkọ
iyawo mbẹ lọdọ wọn ? ṣugbọn ọjọ mbọ̀ ni-
gbati a o gbà ọkọ iyawo lọwọ wọn, nigbana
ni nwọn o gbàwẹ.
16 Ko si ẹniti ifi idãsa aṣọ titun lẹ ogbo-
logbó ẹ̀wu ; nitori eyi ti a fi lẹ ẹ o mu
kuro ninu oju ẹ̀lẹ, eyi akisa a si ma ya
siwaju.
17 Bẹ̃ni ko si ẹniti ifi ọti-waini titun sinu
ìgo atijọ ; bikoṣepe ìgo bẹ́, ọti-waini a si
tú jade, ìgo a si ṣegbé ; ṣugbọn ọti-waini
titun ni nwọn ifi sinu ìgo titun, awọn
mejeji a si ṣe dede.
18 ¶ Bi o ti nsọ nkan wọnyi fun wọn,
kiyesi i, ijoye kan tọ̀ ọ wá, o si tẹriba fun
u, wipe, Ọmọbirin mi kú nisisiyi, ṣugbọn
wá fi ọwọ́ rẹ le e, on o si yè.
19 Jesu dide, o si ba a lọ, ati awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀.
20 ¶ Si kiyesi i, obirin kan ti o nrun
ẹ̀rin ẹ̀jẹ li ọdún mejila, o wá lẹhin rẹ̀, o fi
ọwọ́ kàn iṣẹti aṣọ rẹ̀.
21 O wi ninu ara rẹ̀ pe, Bi mo ba sá le fi
ọwọ́ kàn aṣọ rẹ̀, ara mi o da.
22 Nigbati Jesu si yi ara rẹ̀ pada ti o ri
i, o wipe, Ọmọbirin, túјuka, igbagbọ́ rẹ mu
ọ lara da. A si mu obirin na lara da ni
wakati kanna.
23 Nigbati Jesu si de ile ijoye na, o ba
awọn afunfere ati awọn enia npa ariwo,
24 O wi fun wọn pe, Bila ; nitori ọmọ-
birin na ko kú, sisùn li o sùn. Nwọn si fi
rín ẹrin ẹlẹyà.
25 Ṣugbọn nigbati a si ṣe ti awọn enia
jade, o bọ sile, o si fà ọmọbirin na li ọwọ́
soke ; bẹ̃li ọmọbirin na si dide.
26 Okikí si kàn ká ilẹ na gbogbo.
27 ¶ Nigbati Jesu si jade nibẹ̀, awọn
ọkọnrin afọju meji tọ̀ ọ lẹhin, nwọn kigbe
soke wipe, Iwọ ọmọ Dafidi, ṣãnu fun
wa.
28 Nigbati o si wọ̀ ile, awọn afọju na tọ̀
ọ wá : Jesu bi wọn pe, Ẹnyin gbagbọ́ pe mo
le ṣe eyi ? Nwọn wi fun u pe, Iwọ le ṣe e,
Oluwa.
29 Nigbana li o fi ọwọ́ bà wọn li oju, o
wipe, Ki o ri fun nyin, gẹgẹ bi igbagbọ́
nyin.
30 Oju wọn si là ; Jesu si kìlọ fun wọn
gidigidi, wipe, Kiyesi i, ki ẹ máṣe jẹ ki
ẹnikan ki o mọ̀.
31 Ṣugbọn nigbati nwọn lọ, nwọn ròhin
rẹ̀ yi gbogbo ilu na ká.
32 ¶ Bi nwọn ti njade lọ, wò o, nwọn
mu ọkọnrin odi kan tọ̀ ọ wá, ti o li ẹmi
èṣu.
33 Nigbati a lé ẹmi èṣu na jade, odi si fọ-
hùn ; ẹnu si yà awọn enia, nwọn wipe, A
ko ri irú eyi ri ni Israeli.
34 Ṣugbọn awọn Farisi wipe, agbara
olori awọn ẹmi èṣu li o fi lé awọn ẹmi èṣu
jade.
35 Jesu si rìn si gbogbo ilu-nla ati iletò,
o nkọni ninu sinagogu wọn, o si nwasu
ihin-rere ti ijọba, o si nṣe dida ara ni gbo-
gbo aisan ati gbogbo arùnkarun li ara
awọn enia.
36 ¶ Ṣugbọn nigbati o ri ọ̀pọ enia, inu
rẹ̀ yọ́ si wọn, nitoriti ãrẹ̀ mu wọn, nwọn si
tuká kiri bi awọn agutan ti ko li oluṣọ.
37 Nigbana li o wi fun awọn ọmọ-ẹhin

Digitized by Google

rẹ̀ pe, Lõtọ ni ikorè pọ̀, ṣugbọn awọn ala-
gbaṣe ko to nkan ;
38 Nitorina ẹ gbadura si Oluwa ikorè,
ki o le rán awọn alagbaṣe sinu ikorè rẹ̀.

## ORI 10.

NIGBATI o si pè awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ me-
jejila si ọdọ, o fi agbara fun wọn lori
awọn ẹmi aimọ́, lati ma lé wọn jade, ati
lati ṣe awòtan gbogbo onirũru aisan ati
gbogbo onirũru arùn.
2 Orukọ awọn aposteli mejila na ni
wọnyi : Eyi ekini ni Simoni, ẹniti a npè ni
Peteru, ati Anderu arakọnrin rẹ̀ ; Jakọbu
ọmọ Sebede, ati Johannu arakọnrin rẹ̀ ;
3 Filippi, ati Bartolomeu ; Tomasi, ati
Matteu ti iṣe agbowode ; Jakọbu ọmọ Alfeu,
ati Lebbeu, ẹniti a si npè ni Taddeu.
4 Simoni ara Kana, ati Judasi Iskariotu,
ẹniti o fi i hàn.
5 Awọn mejejila wọnyi ni Jesu rán lọ, o
si paṣẹ fun wọn pe, Ẹ máṣe lọ si ọ̀na awọn
keferi, ati si ilu awọn ará Samaria, ẹ máṣe
wọ̀ ;
6 Ṣugbọn ẹ kuku tọ̀ awọn agutan ile
Israeli ti o nù lọ.
7 Bi ẹnyin ti nlọ, ẹ mã wasu, wipe,
Ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ.
8 Ẹ mã ṣe dida ara fun awọn olokunrùn,
ẹ sọ awọn adẹtẹ̀ di mimọ́, ẹ si jí awọn okú
dide, ki ẹ si ma lé awọn ẹmi èṣu jade : ọfẹ
li ẹnyin gbà, ọfẹ ni ki ẹ fi funni.
9 Ẹ máṣe pèse wura, tabi fadaka, tabi
idẹ sinu asuwọn nyin ;
10 Tabi birigami fun àjo nyin, ati ki ẹ
máṣe mu ẹ̀wu meji, tabi bata, tabi ọpá ipo;
onjẹ oniṣẹ yẹ fun u.
11 Ilu-kilu tabi iletò-kileto ti ẹnyin ba
wọ̀, ẹ bère bi ẹniti o wà nibẹ̀ ba yẹ ; nibẹ̀
ni ki ẹ gbé titi ẹnyin o fi kuro nibẹ̀.
12 Nigbati ẹnyin ba si wọ̀ ile kan, ẹ kí i.
13 Bi ile na ba si yẹ, ki alafia nyin ki o
bà sori rẹ̀ ; bi kò ba yẹ, ki alafia nyin ki o
pada sọdọ nyin.
14 Ẹnikẹni ti kò ba si gbà nyin, ti kò si
gbọ́ ọ̀rọ nyin, nigbati ẹnyin ba jade kuro
ni ile na tabi ni ilu na, ẹ gbọ̀n ekuru ẹsẹ
nyin silẹ.
15 Lõtọ ni mo wi fun nyin, yio san fun
ilẹ Sodomu ati Gomorra li ọjọ idajọ jù fun
ilu na lọ.
16 ¶ Ẹ wò o, mo rán nyin lọ gẹgẹ bi
agutan sarin ikõkò ; nitorina ki ẹnyin ki o
gbọ́n bi ejò, ki ẹ si ṣe oniwà tutù bi àdaba.
17 Ṣugbọn ẹ kiyesi ara nitori enia ; nito-
ri nwọn o mu nyin lọ si ajọ wọn, nwọn o
si nà nyin ninu sinagogu wọn.
18 A o si mu nyin lọ siwaju awọn bãlẹ
ati awọn ọba nitori orukọ mi, fun ẹrí si
wọn ati si awọn keferi.
19 Nigbati nwọn ba si mu nyin lọ siwa-
ju wọn, ẹ máṣe gbèro pe, bawo tabi kili
ẹnyin o wi ; nitoriti a o fi ohun ti ẹnyin o
wi fun nyin ni wakati kanna.
20 Nitoripe ki iṣe ẹnyin li o nsọ, ṣugbọn
Ẹmí Baba nyin ni nsọ ninu nyin.
21 Arakọnrin yio si fi arakọnrin rẹ̀ fun
pipa, ati baba yio si fi ọmọ rẹ̀ fun pipa :
awọn ọmọ yio si dide si awọn õbi wọn,
nwọn o si mu ki a pa wọn.
22 Awọn ọ̀pọ enia yio si korira nyin ni-
tori orukọ mi ; ṣugbọn ẹniti o ba foritì i
titi fi de opin, on na ni a o gbalà.
23 Ṣugbọn nigbati nwọn ba ṣe inunibi-
ni si nyin ni ilu yi, ẹ sá lọ si keji : lõtọ ni
mo sá wi fun nyin, ẹnyin kì o le rekọja
gbogbo ilu Israeli tan titi Ọmọ enia o fi de.
24 Ọmọ-ẹhin kì iṣe jù olukọ rẹ̀ lọ, bẽni
ọmọ-ọdọ ẹni kì ibori oluwa rẹ.
25 O to fun ọmọ-ẹhin ki o dabi olukọ rẹ̀,
ati ọmọ-ọdọ ki o dabi oluwa rẹ̀. Bi nwọn
ba pè bãle ile ni Beelsebubu, melomelo ni
nwọn o pè ara ile rẹ̀ ?
26 Ẹ má fòya wọn nitorina ; nitoriti ko
si ohun ti a bò, ti kì o fi ara hàn ; ati eyi
ti o fi ara sin, ti a ki yio mọ̀.
27 Ohun ti mo ba wi fun nyin li òkun-
kun, on ni ki ẹnyin ki o sọ ni imọlẹ ; ati eyi
ti ẹnyin gbọ́ si etí ni ki ẹ fi wasu lori orule.
28 Ẹ má fòya awọn ẹniti ipa ara, ṣugbọn
ti nwọn ko le pa ọkàn : ṣugbọn ẹ kuku
fòya rẹ̀, ẹniti o le pa ati ara ati ọkàn run li
ọrun apadi.
29 Ologoṣẹ meji ki a ntà ni owo idẹ
wẹ́wẹ meji ? bẽni ko si ọkan ninu wọn ti
yio ṣubu silẹ lẹhin Baba nyin.
30 Ṣugbọn gbogbo irun-iyirun ori nyin
li a kà pe ṣanṣan.
31 Nitorina ẹ má fòya ; ẹnyin ni ère lori
jù ọ̀pọ ologoṣẹ lọ.
32 Nitorina ẹnikẹni ti o ba jẹwọ mi ni-
waju enia, on li emi o jẹwọ pẹlu niwaju
Baba mi ti mbẹ li ọrun.
33 Ṣugbọn bi ẹnikan ba si sẹ mi niwaju
enia, on na li emi o sẹ pẹlu niwaju Baba mi,
ti mbẹ li ọrun.
34 Ẹ máṣe rò pe emi wá rán alafia si
aiye, emi kò wá rán alafia bikoṣe idà.
35 Mo wá lati yà ọmọkọnrin ni ipa si
baba rẹ̀, ati ọmọbirin ni ipa si iya rẹ̀, ati
ayamọ si iyakọ rẹ̀.

Digitized by Google

36 Awọn ọtá enia li awọn ara ile rẹ̀ yio
ma ṣe.
37 Ẹniti o ba fẹ baba tabi iya jù mi
lọ, kò yẹ ni ti emi: ẹniti o ba si fẹ ọmọ-
kọnrin tabi ọmọbirin jù mi lọ, kò si yẹ ni
ti emi.
38 Ẹniti kò ba si gbé agbelebu rẹ̀, ki o
si ma tọ̀ mi lẹhin, kò yẹ ni ti emi.
39 Ẹniti o ba ni ẹmí rẹ̀, yio si sọ ọ nù;
ẹniti o ba si sọ ẹmí rẹ̀ nù nitori mi, on ni
yio si ri i.
40 ¶ Ẹniti o ba gbà nyin, o gbà mi;
ẹniti o ba si gbà mi, o gbà ẹniti o rán
mi.
41 Ẹniti o ba gbà wolĭ li orukọ wolĭ, yio
jẹ ère wolĭ; ẹniti o ba si gbà olododo li
orukọ olododo yio jẹ ère olododo.
42 Ẹnikẹni ti o ba fi ago omi tutù fun
ọkan ninu awọn onirẹlẹ wọnyi mu nitori
kìki orukọ ọmọ-ẹhin, lõtọ ni mo wi fun
nyin, kì o padanù ère rẹ̀.

## ORI 11.

O SI ṣe, nigbati Jesu pari ọ̀rọ rẹ̀ tan fun
awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ mejejila, o ti ibẹ̀
rekọja lati ma kọni, ati lati ma wasu ni ilu
wọn.
2 Nigbati Johannu gbọ́ iṣẹ Kristi ninu
tubu, o rán awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ meji,
3 O si wipe, Iwọ li ẹniti mbọ̀, tabi ki a
ma reti ẹlomiran?
4 Jesu si dahùn o wi fun wọn pe, Ẹ pada
lọ, ẹ si fi ohun wọnyi ti ẹnyin gbọ́, ati eyi
ti ẹnyin ri hàn Johannu.
5 Awọn afọju nriran, awọn amọkun nrìn
ṣaṣa, a nwẹ̀ awọn adẹtẹ̀ mọ́, awọn aditi
ngbọràn, a njí awọn okú dide, ati fun awọn
òtoṣi li a nwasu ihin-rere.
6 Alabukun-fun si li ẹnikẹni, ti kì yio
kọsẹ̀ lara mi.
7 ¶ Nigbati nwọn si lọ, Jesu bẹrẹ si ibi
awọn enia niti Johannu pe, Kili ẹnyin jade
lọ iwò ni ijù? Ifefe ti afẹfẹ nmì?
8 Ani kili ẹnyin jade lọ iwò? ọkọnrin ti
a wọ̀ li aṣọ fẹlẹfẹlẹ? wò o, awọn ẹniti nwọ̀
aṣọ fẹlẹfẹlẹ mbẹ li afin ọba.
9 Ani kili ẹnyin jade lọ iwò? wolĭ?
Lõtọ ni mo wi fun nyin, o si jù wolĭ lọ.
10 Nitori eyiyi li ẹniti a ti kọwe nitori
rẹ̀ pe, Wò o, mo rán onṣẹ mi ṣiwaju rẹ,
ẹniti yio tún ọ̀na rẹ ṣe niwaju rẹ.
11 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Ninu awọn
ti a bí ninu obirin, kò si ẹniti o hù jù
Johannu Baptisti lọ: ṣugbọn ẹniti o si ṣe
ẹni-kerejulọ ni ijọba ọrun o pọ̀ jù u lọ.
12 Lati igba ọjọ Johannu Baptisti wá,
titi o fi di isisiyi ni ijọba ọrun di ifi agbara
wọ̀, awọn alagbara si fi ipá gbà a.
13 Nitori gbogbo awọn wolĭ ati ofin li o
wi tẹlẹ ki Johannu ki o to de.
14 Bi ẹnyin o ba gbà a, eyi ni Elijah, ti
mbọ̀ wá.
15 Ẹniti o ba li etí lati fi gbọ́, ki o
gbọ́.
16 ¶ Ṣugbọn kili emi iba fi iran yi we?
O dabi awọn ọmọ kekere ti njoko li ọjà, ti
nwọn si nkọ si awọn ẹgbẹ wọn,
17 Ti nwọn si nwipe, Awa fun fère fun
nyin ẹnyin kò jó; awa si ṣọ̀fọ fun nyin,
ẹnyin kò sọkun.
18 Nitori Johannu wá, kò jẹ, bẹ̃ni kò si
mu, nwọn wipe, o li ẹmi èṣu.
19 Ọmọ-ẹnia wá, o njẹ, o si nmu, nwọn
wipe, Wò o, ọjẹun, ati ọmọti, ọrẹ́ awọn
agbowode ati awọn ẹlẹṣẹ. Ṣugbọn a dare
fun ọgbọ́n lati ọdọ awọn ọmọ rẹ̀ wá.
20 ¶ Nigbana li o bẹrẹ si iba ilu wọnni
wi, nibiti o gbé ṣe ọ̀pọlọpọ iṣẹ agbara rẹ̀,
nitoriti nwọn kò ronupiwada;
21 Egbé ni fun iwọ, Korasini! egbé ni
fun iwọ, Betsaida! ibaṣepe iṣẹ agbara ti a
ṣe ninu nyin, ki a ti ṣe wọn ni Tire ati
Sidoni, nwọn iba ti ronupiwada lailai ninu
aṣọ ọ̀fọ ati ninu ẽru.
22 Ṣugbọn mo wi fun nyin, yio san fun
Tire pẹlu Sidoni li ọjọ idajọ jù fun ẹnyin
lọ.
23 Ati iwọ, Kapernaumu, ti a gbé ga
soke ọrun li a o si rẹ̀ silẹ si ọrun apãdi:
ibaṣepe gbogbo iṣẹ agbara ti a ti ṣe ninu rẹ,
ki a ti ṣe wọn ninu Sodomu, on iba wà titi
di oni.
24 Ṣugbọn mo wi fun nyin, yio san fun
ilẹ Sodomu li ọjọ idajọ jù fun iwọ lọ.
25 ¶ Lakokò na ni Jesu dahùn, o si
wipe, Mo dupẹ lọwọ rẹ, Baba, Oluwa ọrun
on aiye, nitoriti iwọ pa nkan wọnyi mọ́
kuro li oju awọn ọlọ́gbọn ati amoye, iwọ si
fi wọn hàn fun awọn ọmọ-ọwọ.
26 Gẹgẹ bẹ̃ na ni, Baba, nitori bẹ̃li o tọ́
li oju rẹ.
27 Ohun gbogbo li a fifun mi lati ọdọ
Baba mi wá: kò si si ẹniti o mọ̀ Ọmọ, bi-
kọṣe Baba; bẹ̃ni kò si ẹniti o mọ̀ Baba
bikọṣe Ọmọ, ati ẹnikẹni ti Ọmọ fẹ fi i hàn
fun.
28 ¶ Ẹ wá sọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣiṣẹ,
ti a si di ẹrù wuwo le lori, emi o si fi isimi
fun nyin.
29 Ẹ gbà àjaga mi si ọrùn nyin, ki ẹ si
ma kọ́ ẹkọ́ ti emi; nitori oninu titẹ́ ati

Digitized by Google

oninu tutù li emi; ẹnyin ↄ si ri isimi fun
ọkàn nyin.
30 Nitori àjaga mi rọrun, ẹrù mi si
fuyẹ.

## ORI 12.

LAKOKÒ na ni Jesu là ãrin oko ọkà lọ
li ọjọ isimi; ebi si npa awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀, nwọn si bẹ̀rẹ si ima ya ipẹ́ ọkà, nwọn si
njẹ.
2 Ṣugbọn nigbati awọn Farisi ri i, nwọn
wi fun u pe, Wò o, awọn ọmọ-ẹhin rẹ nṣe
eyi ti kò yẹ lati ṣe li ọjọ isimi.
3 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin kò ti kà
ohun ti Dafidi ṣe, nigbati ebi npa a, ati
awọn ti mbẹ lọdọ rẹ̀;
4 Bi o ti wọ̀ ile Ọlọrun lọ, ti o si jẹ
akara ifihàn, eyiti kò tọ́ fun u lati jẹ, ati
fun awọn ti mbẹ lọdọ rẹ̀, bikoṣe fun kìki
awọn alufa?
5 Tabi ẹnyin kò ti kà a ninu ofin, bi
awọn alufa ti o wà ni tempili ti mbà ọjọ
isimi jẹ ti nwọn si wà li aijẹbi?
6 Ṣugbọn mo wi fun nyin pe, ẹni ti o jù
tempili lọ mbẹ nihin.
7 Ṣugbọn ẹnyin iba mọ̀ ohun ti eyi jẹ:
Ãnu li emi nfẹ, ki iṣe ẹbọ; ẹnyin kì ba ti
dá awọn alailẹṣẹ lẹbi.
8 Nitori ti Ọmọ-ẹnia jẹ́ Oluwa ọjọ isimi
pẹlu.
9 Nigbati o si rekọja nibẹ̀, o lọ sinu
sinagogu wọn.
10 ¶ Si kiyesi i, ọkọnrin kan wa nibẹ̀,
ti ọwọ́ rẹ̀ kan rọ. Nwọn si bi i pe, O ha
tọ́ lati ṣe dida ara li ọjọ isimi? ki nwọn ki
o le fẹ ẹ li ẹfẹ́.
11 O si wi fun wọn pe, Ọkọnrin wo ni
iba ṣe ninu nyin, ti o li agutan kan, bi o
ba si bọ́ sinu ihò li ọjọ isimi, ti kì yio si dì
i mu lati fà a soke?
12 Njẹ melomelo li enia sian jù agutan
lọ? nitorina li o ṣe tọ́ lati ma ṣe rere li ọjọ
isimi.
13 Nitorina li o wi fun ọkọnrin na pe,
Nà ọwọ́ rẹ? on si nà a; ọwọ́ rẹ̀ si pada bọ̀
sipò rẹ̀ gẹgẹ bi ekeji.
14 ¶ Nigbana li awọn Farisi jade lọ,
nwọn si gbìmọ nitori rẹ̀, bi awọn iba ti ṣe
pa a.
15 Nigbati Jesu si mọ̀, o yẹ̀ ara rẹ̀ kuro
nibẹ̀: ọ̀pọ ijọ enia ntọ̀ ọ lẹhin, o si ṣe dida
ara fun gbogbo wọn;
16 O si kìlọ fun wọn pe, ki nwọn ki o
máṣe fi on hàn:
17 Ki eyi ti a ti ẹnu wolĭ Isaiah wi ki o
ba le ṣẹ, pe,
18 Ẹ wò iranṣẹ mi, ẹniti mo yàn; ayanfẹ
mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi: Emi o fi
ẹmí mi fun u, yio si fi idajọ hàn fun awọn
keferi.
19 On kì yio jà, kì yio si kigbe; bẽli
ẹnikẹni kì yio gbọ́ ohùn rẹ̀ ni igboro.
20 Iye fifọ́ ni on kì yio ṣẹ́, owu fitila ti
nru ẽfin ni on kì yio si pa, titi yio fi mu
idajọ di iṣẹgun.
21 Orukọ rẹ̀ li awọn keferi yio ma gbẹ-
kẹle.
22 ¶ Nigbana li a gbé ọkọnrin kan ti o li
ẹmi èṣu, ti o fọju, ti o si yadi, wá sọdọ rẹ̀;
o si mu u lara da tobẹ̃ ti afọju ati odi na
sọ̀rọ, o si riran.
23 Ẹnu si yà gbogbo enia, nwọn si wipe,
Ọmọ Dafidi kọ́ yi?
24 Ṣugbọn nigbati awọn Farisi gbọ́,
nwọn wipe, Eyiyi kò lé awọn ẹmi èṣu
jade, bikoṣe nipa Beelsebubu, olori awọn
ẹmi èṣu.
25 Jesu si mọ̀ ìronu wọn, o si wi fun
wọn pe, Gbogbo ijọba ti o yà ara rẹ̀ ni ipa,
a sọ ọ di ahoro; ati gbogbo ilu, tabi ile ti
o yà ara rẹ̀ ni ipa kì yio le duro.
26 Bi Satani ba si nlé Satani jade, o
yapa si ara rẹ̀; ijọba rẹ̀ yio ha ṣe le duro?
27 Bi o ba si ṣepe ọlá Beelsebubu li emi
fi nlé awọn ẹmi èṣu jade, ọlá tali awọn ọmọ
nyin fi nlé wọn jade? nitorina ni nwọn o
fi ma ṣe onidajọ nyin.
28 Ṣugbọn bi o ba ṣepe Ẹmí Ọlọrun li
emi fi nlé awọn ẹmi èṣu jade, njẹ ijọba
Ọlọrun de si nyin.
29 Tabi ẹnikan yio ti ṣe wọ̀ ilẹ ọkọnrin
alagbara kan, ki o si kó o li ẹrù lọ, biko-
ṣepe o kọ dì ọkọnrin alagbara na li okùn?
nigbana ni yio le kó o ni ile.
30 Ẹniti kò ba bá mi gbé, o nṣe òdi
si mi; ẹniti kò ba si bá mi kopọ̀, o fọn
ká.
31 ¶ Nitorina ni mo wi fun nyin, gbo-
gbo irú ẹ̀ṣẹ-kẹṣẹ ati ọ̀rọ buburu li a o darijì
enia; ṣugbọn ọ̀rọ buburu si Ẹmí Mimọ́, on
li a kì yio darijì enia.
32 Ẹnikẹni ti o ba sọ ọ̀rọ buburu si Ọmọ-
enia, a o dari rẹ̀ jì i; ṣugbọn ẹnikẹni ti o
ba sọ ọ̀rọ buburu si Ẹmí Mimọ́, a kì yio
dari rẹ̀ jì i li aiye yi, ati li aiye ti mbọ̀.
33 Sọ igi di rere, eso rẹ̀ a si di rere,
tabi sọ igi di buburu, eso rẹ̀ a si di bu-
buru: nitori nipa eso li ã fi mọ̀ igi.
34 Ẹnyin ọmọ paramọlẹ, ẹnyin ti iṣe
enia buburu yio ti ṣe le sọ̀rọ rere? nitori
ninu ọ̀pọlọpọ ohun inu li ẹnu isọ.
35 Enia rere lati inu iṣura rere àiya rẹ̀-

ni imu ohun rere jade wá: ati enia bu-
buru lati inu iṣura buburu ni imu ohun
buburu jade wá.
36 Ṣugbọn mo wi fun nyin pe, gbogbo
ọ̀rọ buburu ti enia nsọ, nwọn o jihin rẹ̀ li
ọjọ idajọ.
37 Nitori nipa ọ̀rọ rẹ li a o fi da iwọ
lare, nipa ọ̀rọ rẹ li a o si fi da iwọ lẹbi.
38 ¶ Nigbana li awọn ọkan ninu awọn
akọwe ati Farisi dahùn, wipe, Olukọni,
awa nfẹ ri àmi lọdọ rẹ.
39 Ṣugbọn o dahùn o si wi fun wọn pe,
Iran buburu ati iran panṣaga nfẹ ri àmi;
kò si àmi ti a o fi hàn a, bikoṣe àmi Jona
wolĩ.
40 Nitori bi Jona ti gbé ọsán mẹta ati
oru mẹta ninu ẹja; bẽli Ọmọ-enia yio gbé
ọsán mẹta on oru mẹta ni inu ilẹ.
41 Awọn ara Ninefe yio dide si iran yi
li ọjọ idajọ, nwọn o si da a lẹbi: nitori
nwọn ronupiwada nipa iwasu Jona; si wò
o, ẹniti o pọ̀ ju Jona lọ mbẹ nihinyi.
42 Ayaba gusù yio dide si iran yi li ọjọ
idajọ, yio si da a lẹbi: nitori o ti ikangun
aiye wá igbọ́ ọgbọ́n Solomoni; si wò o,
ẹniti o pọ̀ ju Solomoni lọ mbẹ nihinyi.
43 Nigbati ẹmi aimọ́ kan ba jade kuro
lara enia, ama rìn kiri ni ibi gbigbẹ, ama
wá ibi isimi, kì si iri.
44 Nigbana ni iwipe, Emi o yipada lọ si
ile mi, nibiti mo gbé ti jade wá; nigbati o
si de, o bá a, o ṣofo, a gbá a mọ́, a si ṣe e li
ọṣọ.
45 Nigbana li o lọ, o si mu ẹmi meje
miran pẹlu ara rẹ̀, ti o buru jù on tikararẹ̀
lọ; nwọn bọ si inu rẹ̀, nwọn si ngbé ibẹ̀:
asiwa ọkọnrin na si buru jù ti iṣaju rẹ̀
lọ. Gẹgẹ bẽni yio ri fun iran buburu yi
pẹlu.
46 ¶ Nigbati o nsọ̀rọ wọnyi fun awọn
enia, wò o, iya rẹ̀ ati awọn arakọnrin rẹ̀
duro lode, nwọn nfẹ ba a sọ̀rọ.
47 Nigbana li ẹnikan wi fun u pe, Wõ,
iya rẹ ati awọn arakọnrin rẹ duro lode,
nwọn nfẹ ba ọ sọ̀rọ.
48 Ṣugbọn o dahùn o si wi fun ẹniti o
sọ fun u pe, Tani ni iya mi? ati tani li
awọn arakonrin mi?
49 O si nà ọwọ́ rẹ̀ si awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀,
o wipe, Ẹ wò iya mi ati awọn arakọnrin
mi!
50 Nitori ẹnikẹni ti o ba ṣe ifẹ Baba mi
ti mbẹ li ọrun, on na li arakọnrin mi, ati
arabirin mi, ati iya mi.

ORI 13.

LI ọjọ kanna ni Jesu ti ile jade, o si joko
leti adagun.
2 Ọ̀pọlọpọ ijọ enia pejọ sọdọ rẹ̀, tobẽ ti
o fi bọ sinu ọkọ̀, o joko; gbogbo enia duro
leti adagun.
3 O si fi owe ba wọn sọ̀rọ ohun pipọ o
wipe, Wõ, afọnrugbin kan jade lọ lati fọn
irugbin:
4 Nigbati o fún u, irugbin diẹ bọ́ si ẹba
ọ̀na, awọn ẹiyẹ si wá, nwọn si ṣà a jẹ.
5 Diẹ si bọ́ si ibi okuta, nibiti ko li
erupẹ̀ pipọ; nwọn si sọ jade lọgan, nitoriti
nwọn ko ni ijinlẹ;
6 Nigbati õrùn si goke, nwọn jona:
nitoriti nwọn kò ni gbongbo, nwọn si gbẹ.
7 Diẹ si bọ́ sarin ẹgún; nigbati ẹgún si
dàgba soke, o fún u pa.
8 Ṣugbọn omiran bọ́ si ilẹ rere, o si so
eso, omiran ọgọrọrun, omiran ọgọtọta, omi-
ran ọgbọgbọn.
9 Ẹniti o ba li etí lati fi gbọ́, ki o gbọ́.
10 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si tọ̀ ọ wá, nwọn
bi i pe, Ẽṣe ti iwọ nfi owe ba wọn sọ̀rọ?
11 O si dahùn wi fun wọn pe, nitori
ẹnyin li a fifun lati mọ̀ ohun ijinlẹ ijọba
ọrun, ṣugbọn awọn li a kò fifun.
12 Nitori ẹnikẹni ti o ba ni, on li a o
fifun, on o si ni li ọ̀pọlọpọ; ṣugbọn ẹnikẹni
ti ko ba si ni, lọwọ rẹ̀ li a o si gbà eyi na
ti o ni.
13 Nitorina ni mo ṣe nfi owe ba wọn
sọ̀rọ; nitoriti nwọn nri, nwọn kò si ri,
nwọn ngbọ́, nwọn kò si gbọ́, bẽni kò si yé
wọn.
14 Si ara wọn li ọ̀rọ Isaiah wolĩ si ti ṣẹ,
ti o wipe, Ni gbigbọ́ ẹnyin o gbọ́, kì yio si
yé nyin; ati riri ẹnyin o ri, ẹnyin kì yio
si moye.
15 Nitoriti àiya awọn enia yi sebọ, etí
wọn si wuwo ọ̀ran igbọ́, oju wọn ni nwọn
si dì; nitori ki nwọn ki o má ba fi oju
wọn ri, ki nwọn ki o má ba fi etí wọn gbọ́,
ki nwọn ki o má ba fi àiya wọn mọ̀, ki
nwọn ki o má ba yipada, ki emi ki o má
ba mu wọn lara da.
16 Ṣugbọn ibukun ni fun oju nyin, ni-
toriti nwọn ri; ati fun etí nyin, nitoriti
nwọn gbọ́.
17 Lõtọ ni mo sá wi fun nyin, ọ̀pọlọpọ
wolĩ ati olododo enia ni nfẹ ri ohun ti
ẹnyin ri, nwọn kò si ri wọn; nwọn si nfẹ
gbọ́ ohun ti ẹ gbọ́, nwọn ko si gbọ́ wọn.
18 ¶ Nitorina ẹ gbọ́ owe afọnrugbin.
19 Nigbati ẹnikan ba gbọ́ ọ̀rọ ijọba, ti

Digitized by Google

kò ba si yé e, nigbana li ẹni-buburu nì wá, a si mu eyi ti a fọn si àiya rẹ̀ kuro. Eyi li ẹniti o gbà irugbin lẹba ọ̀na.

20 Ẹniti o si gbà irugbin lori apata, on na li o gbọ́ ọ̀rọ, ti o fi ayọ̀ gbà a kánkan.

21 Ṣugbọn ko ni gbongbo ninu ara rẹ̀, o si pẹ diẹ li akokò kan; nigbati wahalà tabi inunibini dide nitori ọ̀rọ na, nigboṣe a si kọsẹ̀.

22 Eyi pẹlu ti o gbà irugbin sarin ẹgún li ẹniti o gbọ́ ọ̀rọ na; aniyan aiye yi, ati itanjẹ ọrọ̀, fún ọ̀rọ na pa, bẽli o si jẹ alaili eso.

23 Ṣugbọn ẹniti o gbà irugbin si ilẹ rere li ẹniti o gbọ́ ọ̀rọ na, ti o si yé e; on li o si so eso pẹlu, o si so omiran ọgọrọrun, omiran ọgọtọta, omiran ọgbọgbọ̀n.

24 ¶ Owe miran li o pa fun wọn, wipe; Ijọba ọrun dabi ọkọnrin ti o fọ́n irugbin rere si oko rẹ̀:

25 Ṣugbọn nigbati enia sùn, ọtá rẹ̀ wá, o fọ́n èpo buburu sinu alikama, o si ba tirẹ̀ lọ.

26 Ṣugbọn nigbati ẽhu rẹ̀ sọ jade, ti o si so eso, nigbana li èpo buburu fi ara hàn pẹlu.

27 Bẽli awọn ọmọ-ọdọ bãle na tọ̀ ọ wá, nwọn wi fun u pe, Oluwa, irugbin rere ki iwọ fọn sinu oko rẹ? nibo li o ha ti li èpo buburu?

28 O si wi fun wọn pe, Ọtá li o ṣe eyi. Awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ si bi i pe, Iwọ o ha jẹ ki awa ki o lọ tú wọn kuro?

29 O si wipe, Bẹ̃kọ, nigbati ẹnyin ba ntú èpo buburu kuro, ki ẹnyin ki o máṣe tú alikama pẹlu.

30 Ẹ jẹ ki awọn mejeji ki o dàgba pọ̀ titi di igba ikorè: li akokò ikorè emi o wi fun awọn olukore pe, ẹ tète kó èpo buburu jọ, ẹ dì wọn ni ití lati fi iná run wọn; ṣugbọn ẹ kó alikama sinu abà mi.

31 ¶ Owe miran li o pa fun wọn, wipe, Ijọba ọrun dabi wóro irugbin eweko mustardi kan, eyiti ọkọnrin kan mu ti o si sọ sinu oko rẹ̀:

32 Eyiti o kére jù gbogbo irugbin lọ; ṣugbọn nigbati o dàgba, o tobi jù gbogbo ewebẹ lọ, o si di igi, bẽli awọn ẹiyẹ oju ọrun wá, nwọn ngbé ori ẹká rẹ̀.

33 ¶ Owe miran li o pa fun wọn pe, Ijọba ọrun dabi iwukara, ti obirin kan mu, ti o sin sinu oṣuwọn iyẹfun mẹta, titi gbogbo rẹ̀ si fi di wiwu.

34 Gbogbo nkan wọnyi ni Jesu fi powe fun awọn ijọ enia; kò si ba wọn sọ̀rọ bikoṣe li owe:

35 Ki eyiti a ti ẹnu woli sọ ki o ba le ṣẹ, wipe, Emi o yà ọnu mi li owe; emi o sọ nkan wọnni jade ti o ti fi ara pamọ́ lati iṣẹ̀dalẹ aiye wá.

36 Nigbana ni Jesu rán ijọ enia lọ, o si wọ̀ ile; awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si tọ̀ ọ wá, wipe, Sọ idi owe èpo buburu ti oko fun wa.

37 O dahùn o si wi fun wọn pe, Ọmọ-enia li ẹniti nfọn irugbin rere;

38 Oko li aiye; irugbin rere li awọn ọmọ ijọba; ṣugbọn èpo buburu li awọn ọmọ ẹni-buburu nì;

39 Ọtá ti o fọ́n wọn li Èṣu; igbẹhin aiye ni ikorè; awọn angeli si li awọn olukore.

40 Nitorina gẹgẹ bi a ti kó èpo buburu jọ, ti a si fi iná run wọn; bẹ̃ni yio ri ni igbẹhin aiye yi.

41 Ọmọ-ẹnia yio rán awọn angeli rẹ̀, nwọn o kó gbogbo ohun ti o mu ni kọsẹ̀ ni ijọba rẹ̀ kuro, ati awọn ti o ndẹṣẹ.

42 Yio si sọ wọn sinu iná ileru: nibiti ẹkún pẹlu ipahin keke yio gbé wà.

43 Nigbana li awọn olododo yio ma ràn bi õrun ni ijọba Baba wọn. Ẹniti o ba li etí lati fi gbọ́ ki o gbọ́.

44 ¶ Ati pẹlu, ijọba ọrun si dabi iṣura ti a fi pamọ́ sinu oko kan; ti ọkọnrin kan ri, o pa a mọ́, nitori ayọ̀ rẹ̀, o si lọ, o tà gbogbo ohun ti o ni, o rà ilẹ na.

45 ¶ Ati pẹlu, ijọba ọrun si dabi ọkọnrin onişowo kan, ti nwá perli ti o dara gidigidi:

46 Nigbati o ri perli olowo iyebiye kan, o lọ, o si tà gbogbo nkan ti o ni, o si rà a.

47 ¶ Ati pẹlu, ijọba ọrun si dabi àwọn kan, ti a sọ sinu omi okun, ti o si kó oniruru gbogbo.

48 Nigbati o kún, eyi ti nwọn fà soke, nwọn joko, nwọn si kó eyi ti o dara sinu agbọ̀n, ṣugbọn nwọn kó buburu danù.

49 Gẹgẹ bẹ̃ni yio si ri nigbẹhin aiye: awọn angeli yio jade wá, nwọn o yà awọn enia buburu kuro ninu awọn olõtọ,

50 Nwọn o si sọ wọn sinu iná ileru; nibiti ẹkùn ati ipahin keke yio gbé wà.

51 Jesu bi wọn pe, Gbogbo nkan wọnyi yé nyin! Nwọn wi fun u pe, Bẹni, Oluwa.

52 Nigbana li o wi fun wọn pe, Nitorina ni gbogbo akọwe ti a kọ́ sipa ijọba ọrun ṣe dabi ọkọnrin kan ti iṣe bãle, ti o nmu ọtun ati ogbó nkan jade ninu iṣura rẹ̀.

53 ¶ Nigbati o ṣe, ti Jesu pari gbogbo owe wọnyi tan, o ti ibẹ̀ lọ kuro.

54 Nigbati o si de ilu baba rẹ̀, o kọ́ wọn ninu sinagogu wọn, tobẹ̃ ti ẹnu yà gbogbo

Digitized by Google

wọn, nwọn si wipe, Nibo li ọkọnrin yi ti
mu ọgbọ́n ati iṣẹ agbara wọnyi wá ?
55 Ọmọ onișọna igi kọ́ yi ? iya rẹ̀ kọ́ a
npè ni Maria ? ati awọn arakọnrin rẹ̀ kọ́
Jakọbu, Jose, Simoni, ati Juda ?
56 Ati awọn arabirin rẹ̀, gbogbo wọn ki
o mba wa gbé nihinyi ? nibo li ọkọnrin yi
ti di oni gbogbo nkan wọnyi ?
57 Bẽni nwọn korira rẹ. Ṣugbọn Jesu
wi fun wọn pe, Kò si woli ti o wà laili ọlá,
bikoṣe ni ilu ati ni ile on tikararẹ̀.
58 On kò si ṣe ọ̀pọ iṣẹ agbara nibẹ̀, ni-
tori aigbagbọ́ wọn.

## ORI 14.

LI akokò na ni Herodu tetrarki gbọ́
okikí Jesu,
2 O si wi fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ pe, Jo-
hannu Baptisti li eyi ; o jinde kuro ninu
okú ; nitorina ni iṣẹ agbara ṣe hàn lara rẹ̀.
3 ¶ Herodu sá ti mu Johannu, o dè e, o
si fi i sinu tubu, nitori Herodia aya Filippi
arakọnrin rẹ̀.
4 Johannu sá ti wi fun u pe, kò tọ́ fun
iwọ lati ni i.
5 Nigbati o si nfẹ pa a, o bẹ̀ru ijọ enia,
nitoriti nwọn kà a si woli.
6 Ṣugbọn nigbati a nṣe iranti ọjọ ibí
Herodu, ọmọbirin Herodia jó niwaju wọn,
inu Herodu si dùn,
7 Nitorina li o ṣe fi ibura ṣe ileri, wipe,
on o fun u li ohunkohun ti o ba bère.
8 Ẹniti iya rẹ̀ ti kọ́ tẹlẹ ri, o wipe, Fun
mi li ori Johannu Baptisti nihinyi ninu
awopọkọ.
9 Inu ọba si bajẹ : ṣugbọn nitori ibura
rẹ̀, ati awọn ti o bá a joko ti onjẹ, o ni ki a
fi fun u.
10 O si ranṣẹ lọ, o bẹ́ Johannu li ori
ninu tubu.
11 A si gbé ori rẹ̀ wá ninu awopọkọ, a si
fifun ọmọbirin na ; o si gbé e tọ̀ iya rẹ̀ lọ.
12 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si wá, nwọn gbé
okú rẹ̀ sin, nwọn si lọ, nwọn si wi fun
Jesu.
13 ¶ Nigbati Jesu gbọ́, o dide kuro
nibẹ̀, o ba ti ọkọ̀ lọ si ibi ijù kan ; nigbati
awọn enia si gbọ́, nwọn si ti ilu wọn rìn tọ̀
ọ lọ li ẹsẹ.
14 Jesu jade lọ, o ri ọ̀pọlọpọ enia, inu
rẹ̀ si yọ si wọn, o si ṣe dida arùn ara wọn.
15 ¶ Nigbati o di aṣalẹ awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀ tọ̀ ọ wá, wipe, Ibi ijù li eyi, ọjọ si kọja
tan : rán ijọ enia lọ, ki nwọn ki o le lọ si
iletò lọ irà onjẹ fun ara wọn.
16 Ṣugbọn Jesu wi fun wọn pe, Nwọn
ko ni ilọ ; ẹ fun wọn li onjẹ.
17 Nwọn si wi fun u pe, Iṣu akara
marun ati ẹja meji pére li a ni nihinyi.
18 O si wi fun wọn pe, Ẹ mu wọn fun
mi wá nihinyi.
19 O si ni ki a mu ijọ enia joko lori
koko, o si mu iṣu akara marun ati ẹja meji,
nigbati o gbé oju soke, o sure, o si bù u, o
fifun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
si fifun ijọ enia.
20 Gbogbo wọn si jẹ, nwọn si yó ; nwọn
si kó ajẹkù to kù jọ, agbọ̀n mejila kún.
21 Awọn ti o si jẹ ẹ to ìwọn ẹgbẹ̃dọgbọn
ọkọnrin, li aikà awọn obirin ati awọn
ọmọde.
22 ¶ Lojukanna Jesu si rọ̀ awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ lati bọ sinu ọkọ̀, ki nwọn ki o
ṣiwaju rẹ̀ lọ si apakeji, nigbati on tú ijọ
enia ká.
23 Nigbati o si tú ijọ enia ká tan, o gùn
ori òke lọ fun ara rẹ̀, lati gbadura : ni-
gbati alẹ si lẹ, on nikan wà nibẹ̀.
24 Ṣugbọn nigbana li ọkọ̀ wà larin
adagun, ti irumi nti i siwaju ati si ẹhin :
nitoriti afẹfẹ ṣe ọwọ òdi si wọn.
25 Nigbati o di iṣọ kẹrin oru, Jesu tọ̀
wọn lọ, o nrìn loju omi.
26 Nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ ri ti o
nrìn loju omi, ẹ̀ru bà wọn, nwọn wipe,
Iwin ni ; nwọn fi ibẹru kigbe soke.
27 Ṣugbọn lojukanna ni Jesu wi fun wọn
pe, Ẹ tújuka ; Emi ni ; ẹ má bẹ̀ru.
28 Peteru si dá a lohùn, wipe, Oluwa, bi
iwọ ba ni, sọ pe ki emi tọ̀ ọ wá loju omi.
29 O si wipe, Wa. Nigbati Peteru
sọkalẹ lati inu ọkọ̀ lọ, o rìn loju omi lati tọ̀
Jesu lọ.
30 Ṣugbọn nigbati o ri ti afẹfẹ le, ẹ̀ru
ba a ; o si bẹ̀rẹ si irì, o kigbe soke, wipe,
Oluwa, gbà mi.
31 Lojukanna Jesu si nà ọwọ́ rẹ̀, o dì i
mu, o si wi fun u pe, Iwọ onigbagbọ́ ke-
kere, ẽṣe ti iwọ fi nṣiyemeji ?
32 Nigbati nwọn si bọ́ sinu ọkọ̀, afẹfẹ dá.
33 Nigbana li awọn ti mbẹ ninu ọkọ̀
wa, nwọn si fi ori balẹ fun u, wipe, Otitọ
Ọmọ Ọlọrun ni iwọ iṣe.
34 ¶ Nigbati nwọn si rekọja si apakeji,
nwọn de ilẹ awọn ara Genesareti.
35 Nigbati awọn enia ibẹ̀ si mọ̀ pe on ni,
nwọn ranṣẹ lọ si gbogbo ilu na yiká, nwọn
si gbé gbogbo awọn olokunrùn tọ̀ ọ wá.
36 Nwọn bẹ̀ ẹ pe, ki nwọn ki o sá le fi
ọwọ́ kàn iṣẹti aṣọ rẹ̀ : ìwọn gbogbo awọn ti
o si fi ọwọ́ kàn a, di alara dida ṣáṣá.

Digitized by Google

## ORI 15.

NIGBANA li awọn akọwe ati awọn Fa-
risi ti Jerusalemu tọ̀ Jesu wá, wipe,
2 Ẽṣe ti awọn ọmọ-ẹhin rẹ fi nrú ofin
atọwọdọwọ awọn alàgbà? nitoriti nwọn ko
wẹ̀ ọwọ́ wọn nigbati nwọn njẹun.
3 Ṣugbọn o dahùn, o si wi fun wọn pe,
Ẽṣe ti ẹnyin pẹlu nfi ofin atọwọdọwọ nyin
rú ofin Ọlọrun?
4 Nitori Ọlọrun sọ̀fin, wipe, Bọ̀wọ fun
baba on iya rẹ: ati ẹniti o fi baba ati iya
rẹ̀ bu, e jẹ ki o kú ikú rẹ̀.
5 Ṣugbọn ẹnyin wipe, Ẹnikẹni ti o ba wi
fun baba tabi iya rẹ̀ pe, Ẹbùn li ohunkohun
ti iwọ iba fi jère lara mi:
6 Ti ko si bọ̀wọ fun baba tabi iya rẹ̀, o
bọ́. Bẽli ẹnyin sọ ofin Ọlọrun di asan nipa
ofin atọwọdọwọ nyin.
7 Agabagebe, otitọ ni Isaiah sọtẹlẹ nipa
ti nyin, wipe,
8 Awọn enia yi nfi ẹnu wọn sunmọ mi,
nwọn si nfi ète wọn bọ̀wọ fun mi; ṣugbọn
àiya wọn jìna si mi.
9 Ṣugbọn lasan ni nwọn ntẹriba fun mi,
ti nwọn nfi ofin enia kọni fun ẹkọ.
10 ¶ O si pè ijọ awọn enia, o si wi fun
wọn pe, Ẹ gbọ́, ẹ si kiyesi i:
11 Kì iṣe ohun ti o wọ̀ni li ẹnu ni isọ
enia di alaimọ́; bikoṣe eyi ti o ti ẹnu jade
wá, eyini ni isọ enia di alaimọ́.
12 Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wá,
nwọn si wi fun u pe, Iwọ mọ̀ pe, awọn
Farisi binu lẹhin igbati nwọn gbọ́ ọ̀rọ yi?
13 O si dahùn, o wi fun wọn pe, Igi-
kigi ti Baba mi ti mbẹ li ọrun kò ba gbìn,
a o fà a tú kuro.
14 Ẹ jọwọ wọn si: afọju ti nfi ọ̀na hàn
afọju ni nwọn. Bi afọju ba si nfi ọ̀na hàn
afọju, awọn mejeji ni yio ṣubu sinu ihò.
15 Nigbana ni Peteru dahùn o si wi fun
u pe, Sọ idi owe yi fun wa.
16 Jesu si wipe, Ẹnyin pẹlu wà li aimoye
di isisiyi?
17 Ẹnyin ko ti mọ̀ pe, ohunkohun ti o
ba bọ si ẹnu lọ si inu ara, a si yà a jade?
18 Ṣugbọn nkan wọnni ti o ti ẹnu jade,
inu ọkàn li o ti wá; nwọn a si sọ ẹnia di
alaimọ́.
19 Nitori lati inu ọkàn ni iro buburu ti
ijade wá, ipania, panṣaga, àgbere, olè, ẹrí
eke, ati ọ̀rọ buburu.
20 Ohun wọnyi ni isọ enia di alaimọ́:
ṣugbọn ki a jẹun li aiwẹwọ́ ko sọ enia di
alaimọ́.
21 ¶ Nigbana ni Jesu ti ibẹ̀ lọ kuro, o si
lọ si àgbegbe Tire on Sidoni.
22 Sá wò o, obirin kan ara Kenaani
ti ẹkùn na wá, o si kigbe pè e, wipe, Oluwa,
iwọ ọmọ Dafidi ṣãnu fun mi; ọmọbirin mi
li ẹmi èṣu nfi irora pupọ̀ daloro gidigidi.
23 Ṣugbọn ko si dá a lohùn kan. Awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀ wá, nwọn bẹ̀ ẹ, wipe, Rán a lọ
kuro, nitoriti o nsọkun tọ̀ wa lẹhin.
24 Ṣugbọn o dahùn wipe, A kò rán mi,
bikoṣe si awọn agutan ile Israeli ti o nù.
25 Nigbana li o wá, o si tẹriba fun u,
wipe, Oluwa, ràn mi lọwọ.
26 Ṣugbọn o dahùn, wipe, Ko tọ́ ki a mu
akara awọn ọmọ, ki a fi i fun ajá.
27 O si wipe, Otitọ ni, Oluwa: ṣugbọn
awọn ajá ama jẹ ẹrún ti o ti ori tabili oluwa
wọn bọ́ silẹ.
28 Nigbana ni Jesu dahùn o si wi fun u
pe, Obirin yi, igbagbọ́ nla ni tirẹ: ki o ri
fun ọ gẹgẹ bi iwọ ti nfẹ. A si mu ọmọbirin
rẹ̀ lara da ṣáṣá ni wakati kanna.
29 Jesu si ti ibẹ̀ lọ kuro, o wá si eti
adagun Galili, o gùn ori òke lọ, o si joko
nibẹ̀.
30 Ọ̀pọ enia si tọ̀ ọ wá pẹlu awọn amọkun,
ati afọju, ati odi, ati alabuku arùn, ati ọ̀pọ
awọn miran, nwọn si sọ̀ wọn kalẹ lẹba ẹsẹ
Jesu, o si ṣe dida ara fun wọn:
31 Tobẹ̃ ti hà ṣe ijọ enia na, nigbati
nwọn ri ti odi nfọhùn, ti alabuku arùn ndi
ọ̀tọtọ, ti amọkun nrìn ṣaṣa, ati ti afọju
nriran: nwọn si yìn Ọlọrun Israeli logo.
32 ¶ Nigbana ni Jesu pè awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀ si ọdọ, o si wipe, Ãnu ijọ enia nṣe mi,
nitoriti o di ijọ mẹta nisisiyi ti nwọn ti wà
lọdọ mi, nwọn ko si li ohun ti nwọn o jẹ:
emi kò si fẹ rán wọn lọ li ebi, ki ãrẹ̀ ki o
máṣe mu wọn li ọ̀na.
33 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si wi fun u pe,
Nibo li awa o ti ri akara to li aginjù, ti yio
fi yó ọ̀pọ enia yi?
34 Jesu wi fun wọn pe, Iṣu akara melo li
ẹnyin ni? Nwọn wipe, Meje, pẹlu ẹja
kekere diẹ.
35 O si ni ki a mu ijọ enia joko ni ilẹ.
36 O si mu iṣu akara meje, ati ẹja na, o
sure, o bù u, o si fifun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀,
awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si fifun ijọ enia.
37 Gbogbo nwọn si jẹ, nwọn si yó: nwọn
si kó ajẹkù ti o kù jọ agbọ̀n meje kún.
38 Awọn ti o jẹ ẹ to ẹgbaji ọkọnrin, li
aikà awọn obirin ati awọn ọmọde.
39 O si rán ijọ enia lọ, o mu ọkọ̀, o lọ si
ẹkùn Magdala.

Digitized by Google

## ORI 16.

AWỌN Farisi pẹlu Sadusi wá, nwọn ndán
a wò, nwọn si nfẹ ki o fi àmi hàn fun
wọn lati ọrun wá.
2 O dahùn o si wi fun wọn pe, Nigbati o
ba di aṣalẹ, ẹnyin a wipe, Ọjọ o dara: nito-
riti oju ọrun pọ́n.
3 Ati li owurọ̀ ẹnyin a wipe, Ọjọ kì yio
dara loni, nitori ti oju ọrun pọ́n, o si ṣú
dẹ̀dẹ. A! ẹnyin agabagebe, ẹnyin le mọ̀
àmi ti oju ọrun; ṣugbọn ẹnyin ko le mọ̀
àmi akokò wọnyi?
4 Iran buburu ati panṣaga nfẹ àmi irí;
ko si si àmi ti a o fi hàn a, bikọse àmi ti
Jona wolĩ. O si fi wọn silẹ, o rekọja lọ.
5 Nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si de apa-
keji, nwọn gbagbé lati mu akara lọwọ.
6 ¶ Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, Ẹ
kiyesi ara, ki ẹ si ma ṣọra nyin nipa iwu-
kara awọn Farisi ati ti awọn Sadusi.
7 Nwọn si mbá ara wọn ṣe aroye, wipe,
Nitoriti awa ko mu akara lọwọ ni.
8 Nigbati Jesu si woye, o wi fun wọn pe,
Ẹnyin oni-kekere igbagbọ́, ẽṣe ti ẹnyin fi
mba ara nyin ngbèro, nitoriti ẹnyin ko mu
akara lọwọ?
9 Kò iti yé nyin di isisiyi, ẹnyin kò si
ranti iṣu akara marun ti ẹlẹgbẹdọgbọn enia,
ati iye agbọ̀n ti ẹnyin si kójọ?
10 Ẹ kò si ranti iṣu akara meje ti ẹlẹ-
gbaji enia, ati iye agbọ̀n ti ẹnyin kójọ?
11 Ẽha ti ṣe ti kò fi yé nyin pe, emi kò
ti itori akara sọ fun nyin pe, ẹ kiyesi ara
nyin nipa iwukara ti awọn Farisi ati ti
awọn Sadusi.
12 Nigbana li o to yé wọn pe, kì iṣe iwu-
kara ti akara li o fi kìlọ fun wọn pe, ki
nwọn ki o kiyesi ara, bikọse ti ẹkọ́ ti awọn
Farisi ati ti awọn Sadusi.
13 ¶ Nigbati Jesu de igberiko Kesarea
Filippi, o bi awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ lẽre, wipe,
Tali awọn enia nfi emi Ọmọ-enia ipè?
14 Nwọn si wi fun u pe, Omiran ni,
Johannu Baptisti ni iwọ; omiran wipe,
Elijah ni; awọn ẹlomiran ni, Jeremiah,
bikọse bẽ ọkan ninu awọn wolĩ.
15 O bi wọn lẽre, wipe, Ṣugbọn tali
ẹnyin nfi emi pè?
16 Simoni Peteru dahùn, wipe, Kristi,
Ọmọ Ọlọrun alãye ni iwọ iṣe.
17 Jesu si dahùn o si wi fun u pe, Ala-
bukunfun ni iwọ Simoni Ọmọ Jona: kì iṣe
ẹran ara ati ẹ̀jẹ li o sá fi eyi hàn ọ, ṣugbọn
Baba mi ti mbẹ li ọrun.
18 Emi si wi fun ọ pẹlu pe, Iwọ ni
Peteru, lori apata yi li emi o kọle ijọ enia
mi si; oju-ọ̀na ọrun apadi kì yio si le bori
rẹ̀,
19 Emi o si fun ọ ni iṣika ijọba ọrun:
ohunkohun ti iwọ ba dè li aiye, a o si dè e
li ọrun: ati ohunkohun ti iwọ ba tú li
aiye, a o si tú u li ọrun.
20 Nigbana li o kìlọ fun awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀ pe, ki nwọn ki o màṣe sọ fun ẹnikan pe,
on ni Jesu ti iṣe Kristi.
21 ¶ Lati igbana lọ ni Jesu ti bẹ̀rẹ si
ifihàn awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, bi on ko ti le
ṣailọ si Jerusalemu, lati jẹ ọ̀pọ ìya lọwọ
awọn alàgba, ati awọn olori alufa, ati awọn
akọwe, ati a o pa on, ati ni ijọ kẹta on o si
jinde.
22 Nigbana ni Peteru mu u, o bẹ̀rẹ si iba
a wi pe, Ki ama ri i, Oluwa, kì yio ri bẽ
si ọ.
23 Ṣugbọn o yipada, o si wi fun Peteru
pe, Kuro lẹhin mi, Satani, ohun ikọsẹ̀ ni
iwọ jẹ fun mi: iwọ ko rò ohun ti iṣe ti
Ọlọrun, bikọse eyi ti iṣe ti enia.
24 ¶ Nigbana ni Jesu wi fun awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ pe, Bi ẹnikan ba nfẹ lati tọ̀ mi lẹ-
hin, ki o sẹ ara rẹ̀, ki o si gbé agbelebu rẹ̀,
ki o si ma tọ̀ mi lẹhin.
25 Nitori ẹnikẹni ti o ba gbà ẹmí rẹ̀ là,
yio sọ ọ nù: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba sọ ẹmí
rẹ̀ nù nitori mi, yio si ri i.
26 Nitoripe ère kini fun enia, bi o le jèrè
gbogbo aiye, ti o si sọ ẹmí ara rẹ̀ nù? tabi
kili enia iba fi ṣe paṣiparọ ọkàn rẹ̀?
27 Nitori Ọmọ-enia yio ti inu ogo Baba
rẹ̀ wá pẹlu awọn angeli rẹ̀; nigbana ni yio
fi ère olukuluku fun u gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀.
28 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹlomiran wà
ninu awọn ti o duro nihinyi, ti kì yio ri
ikú titi nwọn o fi ri Ọmọ-enia ti mbọ̀wá ni
ijọba rẹ̀.

## ORI 17.

LẸHIN ijọ mẹfa Jesu mu Peteru, Jakọbu,
ati Johannu arakọnrin rẹ̀, o si mu wọn
wá sori òke giga li apakan,
2 Ara rẹ̀ si yipada niwaju wọn; oju rẹ̀ si
nràn bi õrùn, aṣọ rẹ̀ si fún, o dabi imọlẹ.
3 Si kiyesi, Mose ati Elijah yọ si wọn,
nwọn mba a sọ̀rọ.
4 Nigbana ni Peteru dahùn, o si wi fun
Jesu pe, Oluwa, o dara fun wa ki awa ma
gbé ihinyi: bi iwọ ba fẹ, jẹ ki awa ki o pa
agọ́ mẹta sihinyi; ọkan fun iwọ, ati ọkan
fun Mose, ati ọkan fun Elijah.
5 Bi o ti nwi lọwọ, kiyesĩ, ikũku mimọ́
ṣiji bò wọn: si wò o, ohùn kan lati inu

Digitized by Google

ikũku wá, ti o wipe, Eyiyi li ayanfẹ Ọmọ
mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi; ẹ ma gbọ́
tirẹ̀.
6 Nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ gbọ́, nwọn
da oju wọn bolẹ nitori ibẹru pupọ̀.
7 Jesu si wá, o fi ọwọ́ bà wọn, o si wipe,
Dide, ẹ má bẹ̀ru.
8 Nigbati nwọn gbé oju soke, nwọn kò
ri ẹnikan, bikoṣe Jesu nikan.
9 Bi nwọn si ti nti ori òke sọkalẹ, Jesu
kìlọ fun wọn pe, Ẹ màṣe sọ̀rọ iran na fun
ẹnikan titi Ọmọ-enia yio fi tun jinde kuro
ninu okú.
10 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ bi i lẽre, wipe,
Ẽṣe ti awọn akọwe fi wipe, Elijah ni yio
tètekọ de?
11 Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Lõtọ
ni, Elijah yio tètekọ de, ti yio mu nkan
gbogbo pada si ipò.
12 Ṣugbọn mo wi fun nyin pe, Elijah ti
de na, nwọn kò si mọ̀ ọ, ṣugbọn nwọn ti ṣe
ohunkohun ti o wù wọn si i. Gẹgẹ bẹ̃ na
pẹlu li Ọmọ-enia yio jìya pupọ̀ lọdọ wọn.
13 Nigbana li o yé awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
pe, Johannu Baptisti li ẹniti o nwi fun
wọn.
14 ¶ Nigbati nwọn de ọdọ ijọ awọn
enia, ọkọnrin kan wá, o kunlẹ fun u, o
nwipe,
15 Oluwa, ṣãnu fun ọmọ mi, nitoriti o
ni iwapa buburu, ti ima ba a jà gidigidi:
nigbakugba ni ima ṣubu sinu iná, ati ni-
gbamiran sinu omi.
16 Mo si mu u wá sọdọ awọn ọmọ-ẹhin
rẹ, nwọn kò si le mu u lara da.
17 Nigbana ni Jesu dahùn, o si wipe,
Iran alaigbagbọ́ ati arekereke yi, emi o ti
ba nyin gbé pẹ to? emi o si ti mu sũru fun
nyin pẹ to? gbé ọmọ rẹ wá ọdọ mi nihinyi.
18 Jesu si ba a wi, bẹ̃li ẹmi èṣu na jade
kuro lara rẹ̀; a si mu ọmọ na lara da lati
igbana lọ.
19 Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin Jesu tọ̀ ọ
wá lẹhin, nwọn bi i pe, Ẽṣe ti awa kò fi le
lé e jade?
20 Jesu si wi fun wọn pe, Nitori aigba-
gbọ́ nyin ni: lõtọ ni mo sá wi fun nyin,
Bi ẹnyin ba ni igbagbọ́ to wóro irú eweko
mustardi, ẹnyin o wi fun òke yi pe, Ṣí ni-
hinyi lọ si ibi bayi yio si ṣẹ; kò si nkan ti
yio ṣoro fun nyin.
21 Ṣugbọn irú eyi ki ijade lọ afi nipa
adura pẹlu àwẹ.
22 ¶ Nigbati nwọn mbẹ ni Galili, Jesu
wi fun wọn pe, A o fi Ọmọ-enia le awọn
enia lọwọ:
23 Nwọn o si pa a, ni ijọ kẹta yio si
jinde. Inu wọn si bajẹ gidigidi.
24 ¶ Nigbati nwọn de Kapernaumu,
awọn ti ngbà owode tọ̀ Peteru wá, wipe,
Baba nyin ki isan owode?
25 O wipe, Bẹ̃ni. Nigbati o si wọ̀ ile,
Jesu ṣiwaju rẹ̀, o bi i pe, Simoni, iwọ ti rò
o si? lọwọ tali awọn ọba aiye ima gbà owo-
de? lọwọ awọn ọmọ wọn, tabi lọwọ alejò?
26 Peteru wi fun u pe, Lọwọ awọn alejò
ni. Jesu wi fun u pe, Njẹ awọn ọmọ a di
omnira.
27 Ṣugbọn ki awa ki o máṣe bí wọn
ninu, iwọ lọ sinu adagun, ki o si sọ ìwọ rẹ
si omi, ki o si fà ẹja ti o tètekọ yọ soke;
nigbati iwọ ba yà a li ẹnu, iwọ o ri owo idẹ
kan nibẹ̀: on ni ki o mu, ki o fifun wọn
fun ti emi ati tirẹ.

## ORI 18.

LAKOKÒ na li awọn ọmọ-ẹhin Jesu tọ̀ ọ
wa, nwọn bi i pe, Tali ẹniti o papọ̀ju
ni ijọba ọrun?
2 Jesu si pè ọmọ kekere kan sọdọ rẹ̀, o
mu u duro larin wọn,
3 O si wi fun wọn pe, Lotọ, ni mo wi
fun nyin, bikoṣepe ẹnyin ba pada, ki ẹ si
dabi awọn ọmọ kekere, ẹnyin kì yio le
wọle ijọba ọrun.
4 Nitorina ẹniti o ba rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ bi
ọmọ kekere yi, on na ni yio papọ̀ju ni ijọ-
ba ọrun.
5 Ẹniti o ba gbà irú ọmọ kekere yi kan,
li orukọ mi, o gbà mi,
6 Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba mu ọkan ninu
awọn kekere wọnyi ti o gbà mi gbọ́ kọsẹ̀,
o ya fun u ki a so ọlọ mọ́ ọ li ọrùn, ki a si
rì i si ibú omi okun.
7 ¶ Egbé ni fun aiye nitori ẹ̀ṣẹ! ohun
ikọsẹ̀ ko le ṣe ki o ma de; ṣugbọn egbé ni
fun oluwarẹ̀ na nipasẹ ẹniti ohun ikọsẹ̀ na
ti wá!
8 Nitorina bi ọwọ́ rẹ tabi ẹsẹ rẹ ba mu ọ
kọsẹ̀ ke e kuro, ki o si mu wọn kuro lara
rẹ; o sàn fun ọ ki o ṣe akewọ, tabí akesẹ
lọ sinu ìye, jù ki o li ọwọ́ meji tabi ẹsẹ me-
ji, ki a gbé ọ jù sinu iná ainipẹkun.
9 Bi oju rẹ ba si mu ọ kọsẹ̀, yọ ọ jade,
ki o si mu u kuro lara rẹ; o sàn fun ọ ki
o lọ sinu ìye li olojukan, jù ki o li oju
meji, ki a gbè ọ sọ sinu iná ọrun apãdi.
10 Kiyesi ara ki ẹnyin má gàn ọkan
ninu awọn kekere wọnyi; nitori mo wi fun
nyin pe, nigbagbogbo li ọrun li awọn ange-
li wọn nwò oju Baba mi ti mbẹ li ọrun.

Digitized by Google

11 Nitori Ọmọ-enia wá lati gbà awọn ti
o ti nù là.
12 Ẹnyin ti rò o si? bi ọkọnrin kan ba
ni ọgọrun agutan, bi ọkan nù ninu wọn, kì
yio fi mọkandilọgọrun iyokù silẹ̀, kì yio lọ
sori òke lọ iwá eyi ti o nù bi?
13 Njẹ bi o ba si ri i, lõtọ ni mo wi fun
nyin, o yọ̀ nitori agutan na yi, jù mọkandi-
lọ̀gọrun iyokù lọ ti ko nù.
14 Gẹgẹbẹ̃ni kì iṣe ifẹ Baba nyin ti mbẹ
li ọrun, ki ọkan ninu awọn kekere wọnyi
ki o ṣegbé.
15 ¶ Pẹlupẹlu bi arakọnrin rẹ ba ṣẹ̀ ọ, lọ
sọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ fun u ti iwọ ti rẹ̀ meji: bi o ba
gbọ́ tirẹ, iwọ mu arakọnrin rẹ bọ̀ sipò.
16 Ṣugbọn bi kò ba gbọ́ tirẹ, nigbana ni
ki iwọ ki o mu ẹnikan tabi meji pẹlu ara
rẹ, ki gbogbo ọ̀rọ li ẹnu ẹlẹri meji tabi
mẹta ba le fi idi mulẹ̀.
17 Bi o ba si kọ̀ lati gbọ́ wọn, wi fun ijọ
enia Ọlọrun: bi o ba si kọ̀ lati gbọ́ ti ijọ
enia Ọlọrun, jẹ ki o dabi keferi si ọ ati
agbowodè.
18 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Ohun-kohun
ti ẹnyin ba dè li aiye, a o dè e li ọrun:
ohunkohun ti ẹnyin ba si tú li aiye, a o tú
u li ọrun.
19 Mo wi fun nyin ẹ̀wẹ pe, Bi ẹni meji
ninu nyin ba fi ohùn ṣọkan li aiye yi niti
ohun-kohun ti nwọn o bère; a o ṣe e fun
wọn lati ọdọ Baba mi ti mbẹ li ọrun wá.
20 Nitori nibiti ẹni meji tabi mẹta ba kó
ara wọn jọ li orukọ mi, nibẹ̀ li emi o wà li
ãrin wọn.
21 ¶ Nigbana ni Peteru tọ̀ ọ wá, o wipe,
Oluwa, nigba melo li arakọnrin mi yio ṣẹ̀
mi, ti emi o si fijì i? titi di igba meje?
22 Jesu wi fun u pe, Emi kò wi fun ọ pe,
Titi di igba meje, bikoṣe Titi di igba ãdọ-
rin meje.
23 ¶ Nitorina ni ijọba ọrun fi dabi ọba
kan ti nfẹ gbà ìro lọwọ awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀.
24 Nigbati o bẹ̀rẹ si iṣiro, a mu ọkan tọ̀
ọ wá, ti o jẹ ẹ li ẹgbarun talenti.
25 Njẹ bi ko ti ni nkan ti yio san, oluwa
rẹ̀ fi aṣẹ fun wọn pe ki a tà a, ati obirin rẹ̀,
ati awọn ọmọ rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o ni,
ki a le san gbese.
26 Nitorina li ọmọ-ọdọ na wolẹ lẹba ẹsẹ
rẹ̀, o bẹ̀ ẹ, wipe, Oluwa, mu sũru fun mi,
emi o san gbogbo rẹ̀ fun ọ.
27 Oluwa ọmọ-ọdọ na si ṣãnu fun u, o
tú u silẹ, o fi gbese na jì i.
28 Ṣugbọn nigbati ọmọ-ọdọ na jade lọ, o
si ri ọkan ninu awọn ọmọ-ọdọ ẹgbẹ rẹ̀, ti o
jẹ ẹ li ọgọrun owo idẹ: o gbé ọwọ́ le e, o
fún u li ọrùn, o wipe, San gbese ti iwọ jẹ
mi.
29 Ọmọ-ọdọ ẹgbẹ rẹ̀ kunlẹ lẹba ẹsẹ rẹ̀, o
bẹ̀ ẹ, wipe, Mu sũru fun mi, emi o san
gbogbo rẹ̀ fun ọ.
30 On kò si fẹ; o lọ, o gbé e sọ sinu
tubu titi yio fi san gbese na.
31 Nigbati awọn iranṣẹ ẹgbẹ rẹ̀ ri eyi ti
a ṣe, ãnu ṣe wọn gidigidi, nwọn lọ, nwọn
si sọ gbogbo ohun ti a ṣe fun oluwa wọn.
32 Nigbati oluwa rẹ̀ pè e tan, o wi fun
u pe, Ã iwọ iranṣẹ buburu yi, Mo fi gbo-
gbo gbese nì jì ọ, nitoriti iwọ bẹ̀ mi:
33 Iwọ kì isi ṣãnu iranṣẹ ẹgbẹ rẹ, gẹgẹ
bi mo ti ṣãnu fun ọ?
34 Oluwa rẹ̀ si binu, o fi i fun awọn oni-
tubu titi yio fi san gbogbo gbese eyi ti o
jẹ ẹ.
35 Bẹ̃ na gẹgẹ ni Baba mi ti mbẹ li ọrun
yio si ṣe fun nyin, bi olukuluku kò ba fi
tọkàn-tọkan rẹ̀ dari ẹ̀ṣẹ arakọnrin rẹ̀ jì i.

## ORI 19.

O SI ṣe, nigbati Jesu pari ọ̀rọ wọnyi tan,
o ti Galili lọ si ẹkùn Judea li oke odò
Jordani.
2 Ọpọ ijọ enia si tọ̀ ọ lẹhin, o si ṣe dida
ara wọn nibẹ̀.
3 ¶ Awọn Farisi si wá sọdọ rẹ̀, nwọn
ndán a wò, nwọn si wi fun u pe, O tọ́ fun
ọkọnrin ki o kọ̀ aya rẹ̀ silẹ nitori ọ̀ran gbo-
gbo?
4 O dahùn o si wi fun wọn pe, Ẹnyin ko
ti kà a pe, ẹniti o dá wọn nigba àtete-kọṣe
o da wọn ti akọ ti abo?
5 O si wipe, Nitori eyi li ọkọnrin yio ṣe
fi baba ati iya rẹ̀ silẹ, yio famọ́ aya rẹ̀;
awọn mejeji a si di ara kan.
6 Nitorina nwọn kì iṣe meji mọ́ bikoṣe
ara kan. Nitorina ohun ti Ọlọrun ba so
ṣọkan, ki ẹnikẹni ki o máṣe yà wọn.
7 Nwọn wi fun u pe, Ẽṣe ti Mose fi aṣẹ
fun wa, wipe, ki a fi iwe ikọsilẹ fun u, ki a
si kọ̀ ọ silẹ?
8 O wi fun wọn pe, Nitori lile àiya nyin
ni Mose ṣe jẹ fun nyin lati ma kọ̀ aya nyin
silẹ, ṣugbọn lati igba àtetekọṣe wá ko ri bẹ̃.
9 Mo si wi fun nyin, ẹnikẹni ti o ba kọ̀
aya rẹ̀ silẹ, bikoṣepe nitori àgbere, ti o si
gbé omiran ni iyawo, o ṣe panṣaga: ẹnikẹni
ti o ba si gbé ẹniti a kọ̀silẹ ni iyawo, o ṣe
panṣaga.
10 ¶ Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wi fun u pe, Bi
ọ̀ran ọkọnrin ba ri bayi si aya rẹ̀, kò ṣànfa-
ni lati gbé iyawo.
11 Ṣugbọn o wi fun wọn pe, Gbogbo

Digitized by Google

enia kò le gbà ọ̀rọ yi, bikoṣe awọn ẹniti a
fi bùn.
12 Awọn iwẹfa miran mbẹ, ti a bí bẽ̀
lati inu iya wọn wá: awọn iwẹfa miran
mbẹ ti awọn araiye sọ di iwẹfa: awọn iwẹfa
si wà, awọn ti o sọ ara wọn di iwẹfa nitori
ijọba ọrun. Ẹniti o ba le gbà a, ki o gbà a.
13 ¶ Nigbana li a gbé awọn ọmọ-ọwọ
wá sọdọ rẹ̀ ki o le fi ọwọ́ kàn wọn, ki o
gbadura: awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si ba wọn wi.
14 Ṣugbọn Jesu ni, Jọwọ awọn ọmọ ke-
kere, ẹ má si ṣe da wọn lẹkun ati wá sọdọ
mi; nitoriti irú wọn ni ijọba ọrun.
15 O si fi ọwọ́ le wọn, o lọ kuro nibẹ̀.
16 ¶ Si kiyesi i, ẹnikan tọ̀ ọ wá, o si wi
fun u pe, Olukọni rere, ohun rere kili emi
o ṣe, ki emi ki o le ni ìye ainipẹkun?
17 O si wi fun u pe, Ẽṣe ti iwọ fi pè mi
li ẹni rere? ẹni rere kan kò si bikoṣe ẹni-
kan, eyini li Ọlọrun: ṣugbọn bi iwọ ba
nfẹ wọ̀ ibi ìye, pa ofin mọ́.
18 O bi i lẽre pe, Ewo? Jesu wipe, Iwọ
kò gbọdọ pa enia; Iwọ kò gbọdọ ṣe pan-
ṣaga; Iwọ kò gbọdọ jale; Iwọ kò gbọdọ
jẹri eke;
19 Bọwọ fun baba on iya rẹ; ati ki iwọ
fẹ aladugbo rẹ bi ara rẹ.
20 Ọmọdekọnrin na wi fun u pe, Gbo-
gbo nkan wọnyi ni mo ti pamọ́ lati igba
ewe mi wá: kili o kù mi kù?
21 Jesu wi fun u pe, Bi iwọ ba nfẹ pé,
lọ tà ohun ti o ni, ki o si fi tọrẹ fun awọn
talakà, iwọ o si ni iṣura li ọrun: si wá ki
o ma tọ̀ mi lẹhin.
22 Ṣugbọn nigbati ọmọdekọnrin na gbọ́
ọ̀rọ na, o jade lọ ni ibinujẹ: nitoriti o li
ọrọ̀ pupọ̀.
23 ¶ Nigbana ni Jesu wi fun awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ pe, Lõtọ ni mo wi fun nyin pe, o
ṣoro gidigidi fun ọlọrọ̀ lati wọ ijọba ọrun.
24 Mo si wi fun nyin ẹ̀wẹ, O rọrun fun
ibakasiẹ lati wọ̀ oju abẹrẹ, jù fun ọlọrọ̀ lati
wọ̀ ijọba Ọlọrun lọ.
25 Nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ gbọ́ ọ, ẹnu
yà wọn gidigidi, nwọn wipe, Njẹ tali o ha
le là?
26 Ṣugbọn Jesu wò wọn, o si wi fun wọn
pe, Enia li eyi ṣoro fun; ṣugbọn fun Ọlọ-
run ohun gbogbo ni ṣiṣe.
27 ¶ Nigbana ni Peteru dahùn, o si wi
fun u pe, Wò o, awa ti fi gbogbo rẹ̀ silẹ,
awa si ntọ̀ ọ lẹhin; njẹ kili awa o ha ni?
28 Jesu si wi fun wọn pe, Lõtọ ni mo
wi fun nyin, pe ẹnyin ti ẹ ntọ̀ mi lẹhin, ni
igba atunbi, nigbati Ọmọ-enia yio joko
lori itẹ́ ogo rẹ̀, ẹnyin o si joko pẹlu lori itẹ́
mejila, ẹnyin o ma ṣe idajọ awọn ẹ̀ya Israeli
mejila.
29 Ati gbogbo ẹniti o fi ile silẹ, tabi
arakọnrin, tabi arabirin, tabi baba, tabi
iya, tabi aya, tabi ọmọ, tabi ilẹ, nitori
orukọ mi, nwọn o ri ọ̀rọrun gbà, nwọn o si
jogún ìye ainipẹkun.
30 Ṣugbọn ọ̀pọ awọn ti o ṣiwaju ni yio
kẹhin; awọn ti o kẹhin ni yio si ṣiwaju.

## ORI 20.

IJỌBA ọrun sá dabi ọkọnrin kan ti iṣe
bãle ile, ti o jade ni kutukutu owurọ̀
lati pè awọn alagbaṣe sinu ọgba ajara rẹ̀.
2 Nigbati o si ba awọn alagbaṣe pinnu
rẹ̀ si owo idẹ kọ̃kan li õjọ, o rán wọn lọ
sinu ọgba ajara rẹ̀.
3 O si jade lakokò wakati ẹkẹta ọjọ, o ri
awọn alairiṣe miran, nwọn duro nibi ọjà,
4 O si wi fun wọn pe; Ẹ lọ si ọgba
ajara pẹlu, ohunkohun ti o ba tọ́ emi o
fifun nyin. Nwọn si mu ọ̀na wọn pọ̀n lọ
sibẹ̀.
5 O tún jade lọ lakokò wakati kẹfa ati
kẹsan ọjọ, o si ṣe bẽ̀.
6 O si jade lọ lakokò wakati kọkanla
ọjọ, o ri awọn alairiṣe miran ti o duro, o
si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi duro lati
onimoni li airiṣe?
7 Nwọn wi fun u pe, Nitoriti kò si ẹni
ti o fun wa li agbaṣe; O wi fun wọn pe,
Ẹ lọ pẹlu sinu ọgba ajara; eyi ti o ba tọ́
li ẹnyin o ri gbà.
8 Nigbati o di oju alẹ, oluwa ọgba ajara
wi fun iriju rẹ̀ pe, Pè awọn alagbaṣe nì, ki
o si fi owo agbaṣe wọn fun wọn, bẹ̀rẹ lati
ẹni-ikẹhin lọ si ti iṣaju.
9 Nigbati awọn ti a pè lakokò wakati
kọkanla ọjọ de, gbogbo wọn gbà owo idẹ
kọ̃kan.
10 Ṣugbọn nigbati awọn ti o ti ṣaju de,
nwọn ṣebi awọn o gbà jù bẽ̀ lọ; olukuluku
wọn si gbà owo idẹ kọ̃kan.
11 Nigbati nwọn gbà a tan, nwọn nkùn
si bãle rere na.
12 Wipe, Awọn ará ikẹhin ṣiṣẹ kìki wa-
kati kan õjọ, iwọ si mu wọn bá wa ṣe
ọgbọgba, awa ti o ti nrù ẹrù, ati ti a si gbà
oru ọjọ.
13 O si da ọkan ninu wọn lohùn pe, Ọrẹ́,
emi ko ṣiṣe si ọ: iwọ ki o ba mi pinnu rẹ̀
si owo idẹ kan li õjọ?
14 Gbà eyi ti iṣe tirẹ, ki o si ma ba tirẹ
lọ: emi o si fifun ikẹhin yi, gẹgẹ bi mo ti
fifun ọ.
15 Kò ha tọ́ ki emi ki o fi nkan ti iṣe ti



Digitized by Google

emi ṣe bi o ti wù mi? oju rẹ korò nitoriti
emi ṣe ẹni rere?
16 Bẹ̃li awọn ẹni ikẹhin yio di ti iwaju,
awọn ẹni iwaju yio si di ti ikẹhin: nitori
ọ̀pọlọpọ li a pè, ṣugbọn diẹ li a o ri yàn.
17 ¶ Jesu si ngoke lọ si Jerusalemu, o
si pè awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ mejila si apakan
li ọ̀na, o si wi fun wọn pe,
18 Wò o, awa ngoke lọ si Jerusalemu;
a o si fi Ọmọ-enia le awọn olori alufa, ati
awọn akọwe lọwọ, nwọn o si da a lẹbi ikú.
19 Nwọn o si fà a le awọn keferi lọwọ
lati fi i ṣe ẹlẹyà, lati nà a, ati lati kàn a
mọ agbelebu: ni ijọ kẹta yio si jinde.
20 ¶ Nigbana ni iya awọn ọmọ Sebede
ba awọn ọmọ rẹ̀ tọ̀ ọ wá, o bẹ̀ ẹ, o si nfẹ
ohun kan li ọwọ́ rẹ̀.
21 O si bi i pe, Kini iwọ nfẹ? O wi
fun u pe, Jẹ ki awọn ọmọ mi mejeji ki o
ma joko, ekini li ọwọ́ ọtún rẹ, ekeji li ọwọ́
òsi ni ijọba rẹ.
22 Ṣugbọn Jesu dahùn, o si wipe, Ẹnyin
ko mọ̀ ohun ti ẹnyin mbère. Ẹnyin le mu
ninu ago ti emi o mu, ati ki a fi baptismu
ti a o fi baptisi mi baptisi nyin? Nwọn
wi fun u pe, Awa le ṣe e.
23 O si wi fun wọn pe, Lõtọ li ẹnyin o
mu ninu ago mi, ati ninu baptismu ti a o
fi baptisi mi li a o si fi baptisi nyin; ṣu-
gbọn lati joko li ọwọ́ ọtún ati li ọwọ́ òsi
mi, kì iṣe ti emi lati fi funni bikoṣepe fun
kìki awọn ẹniti a ti pèse rẹ̀ silẹ fun lati
ọdọ Baba mi wá.
24 Nigbati awọn mẹwa iyokù gbọ́ ọ,
nwọn binu si awọn arakọnrin wọn mejeji.
25 Ṣugbọn Jesu pè wọn sọdọ rẹ̀, o si
wipe, Ẹnyin mọ̀ pe awọn ọba Keferi ama
lò agbara lori wọn, ati awọn ẹni-nla ninu
wọn ama fi ọlá tẹri wọn ba.
26 Ṣugbọn kì yio ri bẹ̃ lãrin-nyin: ṣu-
gbọn ẹnikẹni ti o ba fẹ pọ̀ ninu nyin, ẹ jẹ
ki o ṣe iranṣẹ nyin:
27 Ati ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣe olori ninu
nyin, jẹ ki o ma ṣe ọmọ-ọdọ nyin:
28 Ani gẹgẹ bi Ọmọ-enia kò ti wá ki a
ṣe iranṣẹ fun u, bikoṣe lati mã ṣe iranṣẹ
funni, ati lati fi ẹmi rẹ̀ ṣe iràpada fun
ọpọlọpọ enia.
29 Bi nwọn ti nti Jeriko jade, ọ̀pọ enia
tọ̀ ọ lẹhin.
30 ¶ Si kiyesi i, awọn ọkọnrin afọju
meji joko leti ọ̀na, nigbati nwọn gbọ́ pe
Jesu nrekọja, nwọn kigbe soke, wipe,
Oluwa, iwọ Ọmọ Dafidi, ṣãnu fun wa.
31 Awọn enia si ba wọn wi, nitori ki
nwọn ki o ba le pa ẹnu wọn mọ́: ṣugbọn
nwọn kigbe jù bẹ̃ lọ, wipe, Oluwa, iwọ
Ọmọ Dafidi, ṣãnu fun wa.
32 Jesu si dẹsẹ duro, o pè wọn, o si
wipe, Kili ẹnyin nfẹ ki emi ki o ṣe fun
nyin?
33 Nwọn wi fun u pe, Oluwa, ki oju wa
ki o le là.
34 Bẹ̃ni Jesu ṣãnu fun wọn, o si fi ọwọ́
tọ́ wọn li oju: lọgan oju wọn si là, nwọn
si tọ̀ ọ lẹhin.

## ORI 21.

NIGBATI nwọn sunmọ eti Jerusalemu,
ti nwọn de Betfage li òke Olifi, ni-
gbana ni Jesu rán awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ meji
lọ,
2 O wi fun wọn pe, Ẹ lọ si iletò ti o
kọju si nyin, nisisiyi ẹnyin o ri kẹtẹkẹtẹ
kan ti a so, ati ọmọ rẹ̀ pẹlu: ẹ tú wọn, ki
ẹ si fà wọn fun mi wá.
3 Bi ẹnikẹni ba si wi nkan fun nyin,
ẹnyin o wi pe, Oluwa ni ifi wọn ṣe; lọgán
ni yio si rán wọn wá.
4 Gbogbo eyi li a ṣe, ki eyi ti a ti sọ
lati ẹnu woli wá ki o le ṣẹ, pe,
5 Ẹ sọ fun ọmọbirin Sioni pe, Kiyesi i,
Ọba rẹ mbọ̀ wá sọdọ rẹ, o tẹnu, o joko lori
kẹtẹkẹtẹ, ati lori ọmọ kẹtẹkẹtẹ.
6 Awọn ọmọ-ẹhin na si lọ, nwọn ṣe bi
Jesu ti wi fun wọn,
7 Nwọn si fà kẹtẹkẹtẹ na wá, ati ọmọ
rẹ̀, nwọn si tẹ́ aṣọ wọn si ẹhin wọn, nwọn
si gbé Jesu kà a.
8 Ọ̀pọ ijọ enia tẹ́ aṣọ wọn si ọ̀na; ẹlo-
miran ṣẹ́ ẹká igi wẹ́wẹ, nwọn si fọn wọn si
ọ̀na.
9 Ijọ enia ti nlọ niwaju, ati eyi ti ntọ̀
wọn lẹhin, nkigbe wipe, Hosanna fun Ọmọ
Dafidi: Olubukun li ẹniti o mbọ̀ wá li
orukọ Oluwa; Hosanna loke ọrun.
10 Nigbati o de Jerusalemu, gbogbo ilu
mìtiti, wipe, Tani yi?
11 Ijọ enia si wipe, Eyi ni Jesu woli
Nasareti ti Galili.
12 ¶ Jesu si wọ̀ inu tempili lọ, o lé gbo-
gbo awon ẹniti ntà, ati ẹniti nrà ni tempili
jade, o si yi tabili awọn onipaṣiparọ owo
danù, ati ibujoko awọn ti ntà ẹiyẹle,
13 O si wi fun wọn pe, A kọwe rẹ̀ pe,
Ile adura li a o ma pè ile mi; ṣugbọn ẹnyin
ti sọ ọ di ihò olè.
14 Ati awọn afọju ati awọn amọkun wá
sọdọ rẹ̀ ni tempili; o ṣe dida ara fun wọn.
15 Nigbati awọn olori alufa ati awọn
akọwe ri ohun iyanu nla ti o ṣe, ati awọn

Digitized by Google

ọmọ kekere nke ni tempili, wipe, Hosanna
fun Ọmọ Dafidi; o bà wọn ninu jẹ gidigidi,
16 Nwọn si wi fun u pe, Iwọ gbọ́ eyiti
awọn wọnyi nwi? Jesu si wi fun wọn pe,
Bẽni: ẹnyin kò ti kà a ninu iwe pe, Lati
ẹnu awọn ọmọ agbo ati awọn ọmọ-ọmu ni
iwọ ti mu iyìn pé?
17 ¶ O si fi wọn silẹ, o jade kuro ni ilu
na lọ si Betani; o wọ̀ sibẹ̀.
18 Nigbati o di owurọ̀, bi o ti npada bọ̀
si Jerusalemu, ebi npa a.
19 Nigbati o ri igi ọ̀pọtọ li ọ̀na, o lọ
sibẹ̀, kò si ri ohun kan lori rẹ̀, bikoṣe kìki
ewé, o si wi fun u pe, Ki eso ki o má so lori
rẹ lati oni lọ titi lailai. Lojukanna igi
ọpọtọ na wọwe.
20 Nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ ri i, ẹnu
yà wọn, nwọn wipe, Igi ọpọtọ yi ma ya
wọwe danù!
21 Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Lõtọ
ni mo wi fun nyin, Bi ẹnyin ba ni igbagbọ́,
ti ẹ kò ba ṣiyemeji, ẹnyin kì yio ṣe kìki eyi
ti a ṣe si igi ọpọtọ yi, ṣugbọn pẹlu bi ẹnyin
ba wi fun òke yi pe, Iwọ ṣidi, ki o si bọ́
sinu okun; yio ṣẹ.
22 Ati ohunkohun gbogbo ti ẹnyin ba fi
adura bère ni igbagbọ́, ẹnyin o ri gbà.
23 ¶ Nigbati o si de inu tempili, awọn
olori alufa ati awọn alàgba enia wá sọdọ rẹ̀
bi o ti nkọ́ awọn enia, nwọn wipe, Ọlá kini
iwọ fi nṣe nkan wọnyi? tali o si fun ọ li ọlá
yi?
24 Jesu si dahùn o si wi fun wọn pe,
Emi o si bi nyin lẽre ohun kan pẹlu, bi
ẹnyin ba sọ fun mi, emi o si sọ fun nyin li
ọlá ti emi fi nṣe nkan wọnyi.
25 Baptismu ti Johannu, nibo li o ti wá?
lati ọrun wá ni, tabi lọdọ enia? Nwọn si
ba ara wọn gbèro, wipe, Bi awa ba wipe,
Lati ọrun wá ni; on o wi fun wa pe, Eha
ti ṣe ti ẹnyin ko fi gbà a gbọ́?
26 Ṣugbọn bi awa ba si wipe, Lọdọ enia;
awa mbẹ̀ru awọn enia; nitori gbogbo wọn
kà Johannu si wolĩ.
27 Nwọn si da Jesu lohùn, wipe, Awa ko
mọ̀. O si wi fun wọn pe, Njẹ emi kì yio si
wi fun nyin li ọlá ti emi fi nṣe nkan wọnyi.
28 ¶ Ṣugbọn kili ẹnyin nrò? Ọkọnrin
kan wà ti o li ọmọ ọkọnrin meji; o tọ̀ ekini
wá, o si wipe, Ọmọ, lọ iṣiṣẹ loni ninu ọgba
ajara mi.
29 O si dahùn wipe, Emi kì yio lọ:
ṣugbọn o ronu nikẹhin, o si lọ.
30 O si tọ̀ ekeji wá, o si wi bẹ̃ gẹgẹ. O
si dahùn wi fun u pe, Emi o lọ, baba: kò
si lọ.
31 Ninu awọn mejeji, ewo li o ṣe ifẹ baba
rẹ̀? Nwọn wi fun u pe, Eyi ekini. Jesu
si wi fun wọn pe, Lõtọ ni mo wi fun nyin,
awọn agbowode ati awọn panṣaga ṣiwaju
nyin lọ si ijọba Ọlọrun.
32 Nitori Johannu ba ọ̀na ododo tọ̀ nyin
wá, ẹnyin kò si gbà a gbọ́: ṣugbọn awọn
agbowode ati awọn panṣaga gbà a gbọ́:
ṣugbọn ẹnyin, nigbati ẹnyin si ri i, ẹ kò
ronupiwada nikẹhin, ki ẹ le gbà a gbọ́.
33 ¶ Ẹ gbọ́ owe miran: Bãle ile kan wà
ti o gbìn ajara, o si sọgba yi i ká, o wà ibi
ifunti sinu rẹ̀, o kọ́ ile-iṣọ, o si fi ṣe agba-
tọju fun awọn oluṣọgba, o si lọ si ajò.
34 Nigbati akokò eso sunmọ etile, o rán
awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ si awọn oluṣọgba na, ki
nwọn ki o le gbà wa ninu eso rẹ̀.
35 Awọn oluṣọgba si mu awọn ọmọ-ọdọ
rẹ̀, nwọn lù ekini, nwọn pa ekeji, nwọn si
sọ ẹkẹta li okuta.
36 O si tun rán awọn ọmọ-ọdọ miran ti o
jù awọn ti iṣaju lọ: nwọn si ṣe bẹ̃ si wọn
gẹgẹ.
37 Ṣugbọn ni ikẹhin gbogbo wọn, o rán
ọmọ rẹ̀ si wọn, o wipe, Nwọn o ṣe ojusaju
fun ọmọ mi.
38 Ṣugbọn nigbati awọn oluṣọgba ri ọmọ
na, nwọn wi fun ara wọn pe, Eyiyi li arole;
ẹ wá, ẹ jẹ ki a pa a, ki a si kó ogún rẹ̀.
39 Nwọn si mu u, nwọn wọ́ ọ jade kuro
ninu ọgbà ajara na, nwọn si pa a.
40 Njẹ nigbati oluwa ọgbà ajara ba de,
kini yio ṣe si awọn oluṣọgba wọnni?
41 Nwọn wi fun u pe, Yio pa awọn enia
buburu wọnni run ni ipa òṣi, yio si fi ọgbà
ajara rẹ̀ ṣe agbatọju fun oluṣọgba miran,
awọn ti o ma fi eso rẹ̀ fun u lakokò.
42 Jesu wi fun wọn pe, Ẹnyin ko ti kà a
ninu Iwe mimọ́ pe, Okuta ti awọn ọ̀mọle
kọ̀ silẹ, on na li o si di pàtaki igun ile: eyi
ni iṣe Oluwa, o si jẹ iyanu li oju wa?
43 Nitorina emi wi fun nyin pe, A o
gbà ijọba Ọlọrun lọwọ nyin, a o si fifun
orilẹ-ede kan ti yio si ma mu eso rẹ̀ jade
wá.
44 Ẹnikẹni ti o ba ṣubu lù okuta yi yio
fọ́: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ṣubu lù, a o si lọ̀ ọ
lulu.
45 Nigbati awọn olori alufa ati awọn
Farisi gbọ́ owe rẹ̀, nwọn woye pe awọn li o
mba wi.
46 Ṣugbọn nigbati nwọn nwá ọ̀na ati gbé
ọwọ́ le e, nwọn bẹ̀ru awọn enia, nitoriti
nwọn gbà a ṣe wolĩ.

Digitized by Google

## ORI 22.

JESU si dahùn, o si tún fi owe sọ̀rọ fun
wọn pe,
2 Ijọba ọrun dabi ọba kan, ti o ṣe igbe-
yawo fun ọmọ rẹ̀.
3 O si rán awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ lọ ipè awọn
ti a ti pè tẹlẹ si ibi iyawo: ṣugbọn nwọn
kò fẹ wá.
4 O si tún rán awọn ọmọ-ọdọ miran,
wipe, Ẹ wi fun awọn ti a pè pe, Wò o, mo
se onjẹ mi tan: a pa malu ati gbogbo ẹran
abọpa mi, a si ṣe ohun gbogbo tan: ẹ wá si
ibi iyawo.
5 Ṣugbọn nwọn ko fipè nkan, nwọn ba ti
wọn lọ, ọkan si ọ̀na oko rẹ̀, omiran si ọ̀na
òwò rẹ̀:
6 Awọn iyokù si mu awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀,
nwọn ṣe àbuku si wọn, nwọn si lù wọn pa.
7 Nigbati ọba si gbọ́ eyi, o binu: o si
rán awọn ogun rẹ̀ lọ, o pa awọn apania
wọnni run, o si kun ilu wọn.
8 Nigbana li o wi fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀
pe, A se ase iyawo tan, ṣugbọn awọn ti a ti
pè kò yẹ.
9 Nitorina ẹ lọ si ọ̀na opópo, iyekiye
ẹniti ẹ ba ri, ẹ pè wọn wá si ibi iyawo.
10 Bẽli awọn ọmọ-ọdọ wọnni si jade lọ si
ọ̀na opópo, nwọn si kó gbogbo awọn ẹniti
nwọn ri jọ, ati buburu ati rere: ibi ase
iyawo si kún fun awọn alapejẹ.
11 ¶ Nigbati ọba na wá iwò awọn alape-
jẹ, o ri ọkọnrin kan nibẹ̀ ti kò ni aṣọ iyawo:
12 O si bi i pe, Ọrẹ́, iwọ ti ṣe wọ̀ ìhin wá
laini aṣọ iyawo? Kò si le fọhùn.
13 Nigbana li ọba wi fun awọn iranṣẹ rẹ̀
pe, Ẹ dì i tọwọ́ tẹsẹ, ẹ gbé e kuro, ki ẹ si sọ
ọ sinu òkunkun biribiri; nibẹ̀ li ẹkún on
ipahìn keke yio gbé wà.
14 Nitori ọ̀pọlọpọ li a pè, ṣugbọn diẹ li a
o ri yàn.
15 ¶ Nigbana li awọn Farisi lọ, nwọn
gbìmọ bi nwọn o ti ṣe dì i mu li ọ̀rọ rẹ̀.
16 Nwọn si rán awọn ọmọ-ẹhin wọn pẹlu
awọn ọmọ-ẹhin Herodu lọ sọdọ rẹ̀, wipe,
Olukọni, awa mọ̀ pe olotitọ ni iwọ, iwọ si
nkọni li ọ̀na Ọlọrun li otitọ, bẽni iwọ kì
iwoju ẹnikẹni: nitoriti iwọ kì iṣe ojusãju
fun enia kan.
17 Njẹ wi fun wa, Iwọ ti rò o si? o tọ́
lati ma san owode fun Kesari, tabi ko tọ́?
18 Ṣugbọn Jesu mọ̀ ìro buburu wọn, o si
wi fun wọn pe Ẽṣe ti ẹnyin fi ndán mi wò,
ẹnyin agabagebe?
19 Ẹ fi owode kan hàn mi. Nwọn si mu
owo idẹ kan tọ̀ ọ wá.
20 O si bi wọn pe, Aworan ati akọle tali
eyi?
21 Nwọn wi fun u pe, Ti Kesari ni.
Nigbana li o wi fun wọn pe, Njẹ ẹ fi ohun
ti iṣe ti Kesari fun Kesari; ati ohun ti iṣe
ti Ọlọrun fun Ọlọrun.
22 Nigbati nwọn si ti gbọ́ ọ̀rọ wọnyi,
ẹnu yà wọn, nwọn fi i silẹ, nwọn si ba ti
wọn lọ.
23 ¶ Ni ijọ kanna li awọn Sadusi tọ̀ ọ
wá, awọn ti o wipe ajinde okú kò si, nwọn
si bi i,
24 Wipe, Olukọni, Mose wipe, Bi ẹnikan
ba kú li ailọmọ, ki arakọnrin rẹ̀ ki o ṣu
aya rẹ̀ lopó, ki o le bímọ si ipò arakọnrin
rẹ̀.
25 Awọn arakọnrin meje kan ti wà lọdọ
wa: eyi ekini lẹhin igbati o gbé aya rẹ̀ ni
iyawo, o kú, bi kò ti ni irú-ọmọ, o fi aya rẹ̀
silẹ fun arakọnrin rẹ̀:
26 Gẹgẹ bẽli ekeji pẹlu, ati ẹkẹta titi o
fi de ekeje.
27 Nikẹhin gbogbo wọn, obirin na kú
pẹlu.
28 Njẹ li ajinde oku, aya ti tani yio ha
ṣe ninu awọn mejeje? nitori gbogbo wọn
li o sá ni i.
29 Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Ẹn-
yin ṣina, nitori ẹnyin kò mọ̀ Iwe mimọ, ẹ
kò si mọ̀ agbara Ọlọrun.
30 Nitoripe li ajinde okú, nwọn kì igbe-
yawo, a kì si fi wọn funni ni igbeyawo,
ṣugbọn nwọn dabi awọn angeli Ọlọrun li
ọrun.
31 Ṣugbọn niti ajinde okú, ẹnyin kò ti
kà eyi ti a sọ fun nyin lati ọdọ Ọlọrun wá,
wipe,
32 Emi li Ọlọrun Abrahamu, ati Ọlọ-
run Isaaki, ati Ọlọrun Jakọbu? Ọlọrun
kì iṣe Ọlọrun awọn okú, bikoṣe ti awọn
alãye.
33 Nigbati awọn enia gbọ́ eyi, ẹnu yà
wọn si ẹkọ́ rẹ̀.
34 ¶ Ṣugbọn nigbati awọn Farisi gbọ́
pe, o pa awọn Sadusi li ẹnu mọ́, nwọn pè
ara wọn jọ.
35 Nigbana li ọkan ninu wọn, ti iṣe
amofin, ndán a wò, o si bi i lẽre ọ̀rọ kan,
wipe,
36 Olukọni, ewo li aṣẹ nla ninu ofin?
37 Jesu si wi fun u pe, Ki iwọ ki o fi
gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati
gbogbo inu rẹ, fẹ Ọlọrun Oluwa rẹ.
38 Eyi li ekini ati ofin nla.
39 Ekeji si dabi rẹ̀, Iwọ fẹ ọmọni-keji
rẹ bi ara rẹ.

Digitized by Google

40 Ninu awọn ofin mejeji yi ni gbogbo ofin ati wolī rọ̀ mọ́.
41 ¶ Bi awọn Farisi ti kó ara wọn jọ, Jesu bi wọn,
42 Wipe, Kili ẹnyin nrò ti Kristi si? ọmọ tani iṣe? Nwọn wi fun u pe, Ọmọ Dafidi ni.
43 O wi fun wọn pe, Ẽha ti ṣe ti Dafidi nipa ẹmí fi npè e li Oluwa, wipe,
44 OLUWA wi fun Oluwa mi pe, Iwọ joko li ọwọ́ ọtún mi, titi emi o fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti itisẹ rẹ?
45 Njẹ bi Dafidi ba npè e li Oluwa, ẽha ti ri ti o fi ṣe ọmọ rẹ̀?
46 Kò si si ẹnikan ti o le da a li ohùn ọ̀rọ kan, bẽni kò si ẹniti o jẹ bi i lẽre ohun kan mọ́ lati ọjọ na lọ.

## ORI 23.

NIGBANA ni Jesu wi fun awọn enia, ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀,
2 Pe, Awọn akọwe pẹlu awọn Farisi joko ni ipò Mose:
3 Nitorina gbogbo ohunkohun ti nwọn ba wipe ki ẹnyin kiyesi, ẹ kiyesi i, ki ẹ si ma ṣe wọn; ṣugbọn ẹ máṣe gẹgẹ bi iṣẹ wọn: nitoriti nwọn ama wi, ṣugbọn nwọn kò ma ṣe.
4 Nitoriti nwọn di ẹrù wuwo ti o ṣoro lati rù, nwọn si gbé e kà awọn enia li ejika; ṣugbọn awọn tikara wọn ko jẹ fi ọkan ninu ika wọn kàn ẹrù na.
5 Ṣugbọn gbogbo iṣẹ wọn ni nwọn nṣe nitori ki awọn enia ki o ba le ri wọn: nwọn sọ ọjá awọ iwe wọn di gbigbòro, nwọn bukún iṣẹti aṣọ wọn,
6 Nwọn fẹ ipò ọlá ni ibi ase, ati ibujoko iyìn ni sinagogu,
7 Ati ikíni li ọjà, ati ki awọn enia mã pè wọn pe, Rabbi, Rabbi.
8 Ṣugbọn ki ẹnyin má ṣe jẹ́ Rabbi: nitoripe ẹnikan ni Olukọ nyin, ani Kristi; gbogbo nyin si li arakọnrin.
9 Ki ẹnyin ki o má si pè ẹnikẹni ni baba li aiye: nitori ẹnikan ni Baba nyin, ẹniti mbẹ li ọrun.
10 Ki ẹnyin ki o má si ṣe jẹ olukọni: nitoripe ọkan li Olukọni nyin, ẹniti iṣe Kristi.
11 Ṣugbọn ẹniti o ba papọ̀ju ninu nyin, on ni ki o ṣe iranṣẹ nyin.
12 Ẹniti o ba si gbé ara rẹ̀ ga, a o rẹ̀ silẹ; ẹnikẹni ti o ba si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ on li a o gbé ga.
13 ¶ Ṣugbọn egbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi, agabagebe; nitoriti ẹnyin sé ilẹkun ijọba ọrun mọ́ awọn enia: ẹnyin tikara nyin kò wọle; bẽli ẹnyin kò si jẹ ki awọn ti nwọle ki o bọ́ sile.
14 Egbé ni fun nyin, ẹnyin, akọwe ati Farisi, agabagebe; nitoriti ẹnyin jẹ ile awọn opó run, ati nitori aṣehan ẹ ngbadua gigun: nitorina li ẹnyin o ṣe jẹbi pọ̀ju.
15 Egbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi, agabagebe; nitoriti ẹnyin yi omi ati iyangbẹ ilẹ ká lati sọ enia kan di alawọṣe; nigbati o di bẽ tan, ẹnyin si sọ ọ di ọmọ ọrun-apadi nigba meji jù ara nyin lọ.
16 Egbé ni fun nyin, ẹnyin amọ̀na afọju, ti o wipe Ẹnikẹni ti o ba fi tempili bura, kò si nkan; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba fi wura ti tempili bura, o di ajigbese!
17 Ẹnyin alaimoye ati afọju: ewo li o pọ̀ju, wura, tabi tempili ti o nsọ wura di mimọ́?
18 Ati, Ẹnikẹni ti o ba fi pẹpẹ bura, kò si nkan; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba fi ẹ̀bun ti o wà lori rẹ̀ bura, o di ajigbese!
19 Ẹnyin alaimoye ati afọju: ewo li o pọ̀ju, ẹ̀bun, tabi pẹpẹ ti o nsọ ẹ̀bun di mimọ́?
20 Njẹ ẹnikẹni ti o ba si fi pẹpẹ bura, o fi i bura, ati gbogbo ohun ti o wà lori rẹ̀.
21 Ẹnikẹni ti o ba si fi tempili bura, o fi i bura, ati ẹniti o ngbé inu rẹ̀ pẹlu.
22 Ẹniti o ba si fi ọrun bura, o fi itẹ́ Ọlọrun bura, ati ẹniti o joko lori rẹ̀.
23 Egbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi, agabagebe: nitoriti ẹnyin nsan idamẹwa minti, ati anise, ati kumini, ẹnyin si ti fo ọ̀ran ofin ti o tobi jù kọja, idajọ, ãnu, ati igbagbọ́: wọnyi li o tọ́ ti ẹnyin iba tète ṣe, ẹnyin kì ba si ti fi wọnni silẹ laiṣe.
24 Ẹnyin afọju amọ̀na, ti nsẹ́ kantikanti, ti o si ngbé ibakasiẹ mì.
25 Egbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi, agabagebe; nitoriti ẹnyin wẹ̀ ode ago ati awopọkọ́ mọ́, ṣugbọn inu wọn kún fu irẹjẹ ati ìka.
26 Iwọ afọju Farisi, tète wẹ̀ eyi ti mbẹ ninu ago ati awọpọkọ́ mọ́ na, ki ode wọn ki o le mọ́ pẹlu.
27 Egbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi, agabagede; nitoriti ẹnyin dabi iboji okú funfun, ti o dara li ode lotitọ, ṣugbọn inu wọn kún fun egungun okú enia, ati fun ẹgbin gbogbo.
28 Gẹgẹ bẽli ẹnyin pẹlu fi ara hàn li ode bi awọn olõtọ fun enia, ṣugbọn inu nyin kun fun agabagebe ati fun ẹ̀ṣẹ.

Digitized by Google

29 Egbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi, agabagebe; nitoriti ẹnyin mọle iboji awọn wolĩ, ẹnyin si ṣe isá okú awọn olõtọ li ọṣọ,

30 Ẹnyin ti o wipe, Awa iba wà nigba ọjọ awọn baba wa, awa kì ba li ọwọ́ ninu ẹ̀jẹ awọn wolĩ.

31 Njẹ ẹnyin li ẹlẹri fun ara nyin pe, ẹnyin li awọn ọmọ awọn ẹniti o pa awọn wolĩ.

32 Njẹ ẹnyin kuku kún òṣuwọn awọn baba nyin de oke.

33 Ẹnyin ejò, ẹnyin ọmọ paramọlẹ, ẹnyin o ti ṣe yọ ninu ẹbi ọrun apadi?

34 ¶ Nitorina ẹ kiyesi i, Emi rán awọn wolĩ, ati amoye enia, ati akọwe si nyin: omiran ninu wọn li ẹnyin o pa, ti ẹnyin o si kàn mọ agbelebu; ati omiràn ninu wọn li ẹnyin o nà ni sinagogu nyin, ati ti ẹnyin o ṣe inunibini si lati ilu de ilu:

35 Ki gbogbo ẹ̀jẹ awọn olõtọ, ti a ti ta silẹ li aiye, ba le wà li ori nyin, lati igba ẹ̀jẹ Abeli olõtọ wá fi de ẹ̀jẹ Sakariah, ọmọ Barakiah, ẹniti ẹnyin pa larin tempili ati pẹpẹ.

36 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Gbogbo nkan wọnyi ni yio wá sori iran yi.

37 Jerusalemu, Jerusalemu, iwọ ti o pa awọn wolĩ, ti o si sọ okuta lù awọn ti a rán si ọ pa, igba melo li emi nfẹ radọ bò awọn ọmọ rẹ, bi agbebọ̀ ti iradọ bò awọn ọmọ rẹ̀ labẹ apá rẹ̀, ṣugbọn ẹnyin kò fẹ!

38 Sawò o, a fi ile nyin silẹ fun nyin li ahoro.

39 Mo si wi fun nyin, Ẹnyin kì yio ri mi mọ́ lati isisiyi lọ, titi ẹnyin o fi wi pe, Olubukún li ẹniti o mbọ̀ wá li orukọ Oluwa.

## ORI 24.

JESU si jade lọ, o ti tempili kuro: awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si tọ̀ ọ wá lati fi imọ tempili hàn a.

2 Jesu si wi fun wọn pe, Ẹnyin kò ri gbogbo nkan wọnyi? lõtọ ni mo wi fun nyin, Kì yio si okuta kan nihinyi ti a o fi silẹ lori ekeji, ti a kì yio wó lulẹ.

3 ¶ Bi o si ti joko lori òke Olifi, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ tọ̀ ọ wá nikọ̀kọ, wipe, Sọ fun wa, nigbawo ni nkan wọnyi yio ṣẹ? kini yio si ṣe àmi wíwa rẹ, ati ti opin aiye?

4 Jesu si dahùn, o si wi fun wọn pe, Ẹ mã kiyesi ara, ki ẹnikẹni ki o máṣe tàn nyin jẹ.

5 Nitori awọn enia pipọ yio wá li orukọ mi, wipe, Emi ni Kristi; nwọn o si tàn ọ̀pọlọpọ jẹ.

6 Ẹnyin o si gburo ogun ati idagìri ogun: ẹ kiyesi i, ki ẹnyin ki o máṣe kọnu: nitori gbogbo nkan wọnyi ko le ṣe ki o ma ṣẹ, ṣugbọn opin na ki iṣe isisiyi.

7 Nitoripe orilẹ-ède yio dide si orilẹ-ède, ati ijọba si ijọba: ìyan, ati ajakalẹ arùn, ati isẹlẹ yio si wà ni ibi pipọ.

8 Gbogbo nkan wọnyi ni ipilẹṣẹ ipọnju.

9 Nigbana ni nwọn o fi nyin funni lati jẹ ni ìya, nwọn o si pa nyin: a o si korira nyin lọdọ gbogbo orilẹ-ẹ̀de nitori orukọ mi.

10 Nigbana li ọ̀pọlọpọ yio kọsẹ̀, nwọn o si ma fi ara wọn hàn, nwọn o si korira ara wọn.

11 Wolĩ eke pipọ ni yio si dide, nwọn o si tàn ọ̀pọ enia jẹ.

12 Ati nitori ẹ̀ṣẹ yio di pipọ, ifẹ awọn ọ̀pọ enia yio di tutù.

13 Ṣugbọn ẹniti o ba foritì i titi fi de opin, on na li a o gbalà.

14 A o si wasu ihin-rere ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹlẹri fun gbogbo orilẹ-ède; nigbana li opin yio de.

15 Nitorina nigbati ẹnyin ba si ri irira isọdahoro nì, ti a ti ẹnu wolĩ Danieli sọ, ti o ba duro ni ibi mimọ́ nì, (ẹnikẹni ti o ba kà a, ki oyé ki o yé e:)

16 Nigbana ni ki awọn ti mbẹ ni Judea ki o sálọ si ori òke:

17 Ki ẹniti mbẹ lori ile ki o má sọkalẹ wá lati mu ohunkohun jade ninu ile rẹ̀:

18 Ki ẹniti mbẹ li oko maṣe pada sẹhin wá lati mu aṣọ rẹ̀.

19 Ṣugbọn egbé ni fun awọn ti o lóyun, ati fun awọn ti o nfi ọmú fun ọmọ mu ni ijọ wọnni!

20 Ṣugbọn ẹ mã gbadura ki sisá nyin ki o máṣe bọ́ si igba otutù, ki o má si ṣe ọjọ isimi:

21 Nitori nigbana ni ipọnju nla yio wà, irú eyi ti kò si lati igba ibẹrẹ ọjọ ìwa di isisiyi, bẹ̃kọ, irú rẹ̀ kì yio si si.

22 Bi kò si ṣepe a ke ọjọ wọnni kuru, kò si ẹda ti iba le là a; ṣugbọn nitori awọn ayanfẹ li a o fi ke ọjọ wọnni kuru.

23 Nitorina bi ẹnikan ba wi fun nyin pe, Wò o, Kristi mbẹ nihinyi, tabi lọhun; ẹ máṣe gbà a gbọ́.

24 Nitori awọn eke Kristi, ati eke wolĩ yio dide, nwọn o si fi àmi ati ohun iyanu nla hàn; tobẹ̃ bi o le ṣe nwọn o tàn awọn ayanfẹ pãpã.

25 Kiyesi i, mo wi fun nyin tẹlẹ.

Digitized by Google

26 Nitorina bi nwọn ba wi fun nyin pe,
Sawò o, o wà li aginjù ; ẹ má lọ sibẹ̀ : wò
o, o wà ni ìkọkọ yará ; ẹ máṣe gbàgbọ́.
27 Nitoripe gẹgẹ bi manamana iti ìha
ìla-õrùn kọ sãn, ti isiṃọlẹ ni ìha ìwọ-õrùn ;
gẹgẹ bẹ̃ni wíwa Ọmọ-enia yio ri pẹlu.
28 Nitori ibikibi ti oku ba sá gbé wà,
ibẹ̀ li awọn idì ikojọ pọ̀ si.
29 ¶ Lojukanna lẹhin ipọnju ọjọ wọnni
li õrùn yio ṣõkun, oṣupá ki yio si fi imọlẹ
rẹ̀ hàn, awọn irawọ yio ti oju ọrun já silẹ,
agbara oju ọrun li a o si mì-titi :
30 Nigbana li àmi Ọmọ-enia yio si fi ara
hàn li ọrun : nigbana ni gbogbo orilẹ-ède
li aiye yio kãnu, nwọn o si ri Ọmọ-enia ti
yio ma ti oju ọrun bọ̀ ti on ti agbara ati
ogo nla.
31 Yio si rán awọn angeli rẹ̀ ti awọn ti
ohùn ipè nla, nwọn o si kó gbogbo awọn
ayanfẹ rẹ̀ lati ori igun mẹrẹrin aiye jọ, lati
ikangun ọrun kini lọ de keji.
32 Nisisiyi ẹ kọ́ owe igi ọpọtọ ; Nigbati
ẹká rẹ̀ ba yọ titun, ti o ba si ru ewé, ẹnyin
mọ̀ pe igba ẽrùn sunmọ etile :
33 Gẹgẹ bẹ̃ na li ẹnyin, nigbati ẹnyin ba
ri gbogbo nkan wọnyi, ki ẹ mọ̀ pe o sunmọ
etile tan lẹhin ilẹkun.
34 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Iran yi ki
yio rekọja, titi a o fi mu gbogbo nkan
wọnyi ṣẹ.
35 Ọrun on aiye yio rekọja, ṣugbọn ọ̀rọ
mi ki yio rekọja.
36 ¶ Ṣugbọn niti ọjọ ati wakati na, kò
si ẹnikan ti o mọ̀ ọ, kò si, ki iṣe awọn
angeli ọrun, bikoṣe Baba mi nikanṣoṣo.
37 Ṣugbọn gẹgẹ bi ọjọ Noa ti ri, bẹ̃ni
wíwa Ọmọ-enia yio si ri.
38 Nitori bi ọjọ wọnni ti o wà niwaju
eyi ti a fi omi ri aiye, ti nwọn njẹ, ti
nwọn nmu, ti nwọn ngbé iyawo, nwọn si
nfi funni ni iyawo, titi o fi di ọjọ ti Noa fi
bọ́ sinu ọkọ̀,
39 Nwọn kò si mọ̀ titi omi fi de, ti o
gbá gbogbo wọn lọ ; gẹgẹ bẹ̃ni wíwa Ọmọ-
enia yio ri pẹlu.
40 Nigbana li ẹni meji yio wà li oko ; a
o mu ọkan, a o si fi ekeji silẹ.
41 Awọn obirin meji yio jùmọ ma lọ̀ ọlọ
pọ̀ ; a o mu ọkan, a o si fi ekeji silẹ.
42 ¶ Njẹ ki ẹnyin ki o si ma ṣọra ; ni-
tori ẹnyin kò mọ̀ wakati ti Oluwa nyin yio
de.
43 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o mọ̀ yi pe, bãle
ile iba mọ̀ wakati na ti olè yio wá, iba ma
ṣọna, on ki ba ti jẹ ki a runlẹ ile rẹ̀.
44 Nitorina ki ẹnyin ki o mura silẹ : ni-
tori ni wakati ti ẹnyin kò rò tẹlẹ li Ọmọ-
enia yio de.
45 Tali o ṣe olõtọ ati ọlọgbọn ọmọ-ọdọ,
ẹniti oluwa rẹ̀ fi ṣe olori ile rẹ̀, lati fi onjẹ
wọn fun wọn li akokò ?
46 Alabukún-fun li ọmọ-ọdọ na, nigbati
oluwa rẹ̀ ba de, ẹniti yio bá a ki o ma ṣe
bẹ̃.
47 Lõtọ ni mo wi fun nyin pe, On o fi
ṣe olori gbogbo ohun ti o ni.
48 Ṣugbọn bi ọmọ-ọdọ buburu na ba wi
ninu ara rẹ̀ pe, Oluwa mi fà àbọ rẹ̀ sẹhin ;
49 Ti o si bẹ̀rẹ si ilù awọn ẹgbẹ rẹ̀ ọmọ-
ọdọ, ati si ijẹ ati si imu li amupara ;
50 Oluwa ọmọ-ọdọ na yio de li ọjọ ti kò
fi oju si ọ̀na rẹ̀, ati ni wakati ti kò daba,
51 Yio si jẹ ẹ ni ìya gidigidi, yio yàn
ipa tirẹ̀ pẹlu awọn agabagebe, nibẹ li ẹkún
on ipahinkeke o gbé wà.

## ORI 25.

NIGBANA li a o fi ijọba ọrun wé awọn
wundia mẹwa, ti o mu fitila wọn, ti
nwọn si jade lọ ipade ọkọ iyawo.
2 Marun ninu wọn ṣe ọlọgbọn, marun si
ṣe alaigbọn.
3 Awọn ti o ṣe alaigbọ́n mu fitila wọn,
nwọn kò si mu oróro lọwọ :
4 Ṣugbọn awọn ọlọgbọn mu oróro ninu
kolobo pẹlu fitila wọn.
5 Nigbati ọkọ iyawo pẹ, gbogbo wọn
tõgbé, nwọn si sùn.
6 Nigbati o di arin ọganjọ, igbe ta soke,
wipe, Wò o, ọkọ iyawo mbọ̀ ; ẹ jade lọ
ipade rẹ̀.
7 Nigbana ni gbogbo awọn wundia wọn-
ni dide, nwọn tún fitila wọn ṣe.
8 Awọn alaigbọn si wi fun awọn ọlọ́gbọn
pe, Fun wa ninu oróro nyin ; nitori fitila
wa nku lọ.
9 Ṣugbọn awọn ọlọ́gbọn da wọn li ohùn,
wipe, Bẹ̃kọ ; ki o mãṣe aito fun wa ati
ẹnyin : ṣugbọn ẹ kuku tọ̀ awọn ti ntà lọ,
ki ẹnyin ki o rà fun ara nyin.
10 Nigbati nwọn si nlọ rà, ọkọ iyawo
de ; awọn ti o si mura tan bá a wọle lọ si
ibi iyawo : a si ti ilẹkun.
11 Ni ikẹhin li awọn wundia miran
iyokù si de, nwọn wipe, Oluwa, Oluwa,
ṣilẹkun fun wa.
12 Ṣugbọn o da wọn lohùn, wipe, Lõtọ
ni mo wi fun nyin, emi kò mọ̀ nyin.
13 Njẹ ki ẹnyin ki o mã ṣọra, nitori
ẹnyin ko mọ̀ ọjọ, tabi wakati ti Ọmọ-enia
mbọ̀ wá.
14 ¶ Nitori ijọba orun dabi okonrin

Digitized by Google

kan ti o nlọ si ilu ti o jìna réré, ẹniti o pè awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀, o si kó ẹrù rẹ̀ fun wọn.

15 O si fi talenti marun fun ọkan, o fi meji fun ẹnikeji, ati ọkan fun ẹnikẹta ; o fifun olukuluku gẹgẹ bi agbara rẹ̀ ti ri ; lẹsẹkanna o mu ọ̀na àjo rẹ̀ pọ̀n.

16 Nigbana li eyi ti o gbà talenti marun lọ, o fi tirẹ̀ ṣòwo, o si jère talenti marun miran pẹlu wọn.

17 Gẹgẹ bẹ̃li eyi ti o gbà meji, on pẹlu si jère meji.

18 Ṣugbọn eyi ti o gbà talenti kan lọ, o wà ilẹ, o si rì owo oluwa rẹ̀.

19 Lẹhin igba ti o pẹ titi, oluwa awọn ọmọ-ọdọ wọnni de, o ba wọn ṣiro.

20 Eyi ti o gbà talenti marun si wá, o si mu talenti marun miran wá pẹlu, o wipe, Oluwa, iwọ fi talenti marun fun mi: si wò o, mo jère talenti marun miran le ori wọn.

21 Oluwa rẹ̀ wi fun u pe, O ṣeun, iwọ ọmọ-ọdọ rere ati olotitọ : iwọ ṣe olotitọ ninu ohun kekere, emi o mu ọ ṣe olori ohun ọ̀pọlọpọ: iwọ bọ́ sinu ayọ̀ Oluwa rẹ.

22 Ati eyi ti o gbà talenti meji pẹlu o wá, o si wipe, Oluwa, iwọ fi talenti meji fun mi : wò o, mo jère talenti meji miran le ori wọn.

23 Oluwa rẹ̀ si wi fun u pe, O ṣeun, iwọ ọmọ-ọdọ rere ati olotitọ ; iwọ ṣe olotitọ ninu ohun kekere, emi o mu ọ ṣe olori ohun ọ̀pọlọpọ : iwọ bọ́ sinu ayọ̀ oluwa rẹ.

24 Nigbana li eyi ti o gbà talenti kan de, o ni, Oluwa, emi mọ̀ ọ li onrorò enia, iwọ nkore jọ nibiti iwọ kò gbe fọn irugbin si, iwọ si nṣà nibiti iwọ ko fẹ́ká si :

25 Emi si bẹ̀ru, mo pa talẹnti rẹ mọ́ ninu ilẹ : wò o, ohun ti o ni niyi.

26 Oluwa rẹ̀ dahùn o si wi fun u pe, Iwọ ọmọ-ọdọ buburu ati onilọra, iwọ mọ̀ pe emi nkore nibiti emi kò fọn irugbin si, emi si nṣà nibiti emi kò fẹ́ká si :

27 Nitorina iwọ iba fi owo mi si ọwọ́ awọn ti npowodà, nigbati emi ba de, ki emi ki o ba le gbà nkan mi ti on ti elé.

28 Nitorina ẹ gbà talenti na li ọwọ́ rẹ̀, ẹ fifun eyi ti o ni talenti mẹwa.

29 Nitoripe ẹnikẹni ti o ba ni, li a o si fifun, yio si ni ọ̀pọlọpọ : ṣugbọn li ọwọ́ ẹniti kò ni li a o gbà eyi ti o ni.

30 Ẹ si gbé ọmọ-ọdọ na alailere sọ sinu òkunkun ọhún : nibẹ̀ li ẹkún ati ipahin keke yio gbé wà.

31 ¶ Nigbati Ọmọ-enia yio wá ninu ogo rẹ̀, ati gbogbo awọn angeli mimọ́ pẹlu rẹ̀, nigbana ni yio joko lori itẹ́ ogo rẹ̀ :

32 Niwaju rẹ̀ li a o si kó gbogbo orilẹ-ède jọ : yio si yà wọn si ọ̀tọ kuro ninu ara wọn, gẹgẹ bi oluṣọ agutan ima yà agutan rẹ̀ kuro ninu ewurẹ :

33 On o si fi agutan si ọwọ́ ọtún rẹ̀, ṣugbọn awọn ewurẹ si ọwọ́ òsi.

34 Nigbana li Ọba yio wi fun awọn ti o wà li ọwọ́ ọtun rẹ̀ pe, Ẹ wá ẹnyin alabukun-fun Baba mi, ẹ jogún ijọba, ti a ti pèse silẹ fun nyin lati ọjọ ìwa :

35 Nitori ebi npa mi, ẹnyin si fun mi li onjẹ : ongbẹ ngbẹ mi, ẹnyin si fun mi li ohun mimu : emi ṣe alejò, ẹnyin si gbà mi si ile :

36 Emi wà ni ìhoho, ẹnyin si daṣọ bò mi : emi ṣe aisan, ẹnyin si bojuto mi : emi wà ninu tubu, ẹnyin si tọ̀ mi wá.

37 Nigbana li awọn olotitọ yio dahùn, nwọn o si wipe, Oluwa, nigbawo li awa ri ti ebi npa ọ, ti awa fun ọ li onjẹ ? tabi ti ongbẹ ngbẹ ọ, ti awa fun ọ li ohun mimu ?

38 Nigbawo li awa ri ti iwọ ṣe alejò, ti a gbà ọ si ile ? tabi ti iwọ wà ni ìhoho, ti awa daṣọ bò ọ ?

39 Tabi nigbawo li awa ri ti iwọ ṣe aisan, ti a bojuto ọ ? tabi ti iwọ wà ninu tubu, ti awa tọ̀ ọ wá ?

40 Ọba yio dahùn yio si wi fun wọn pe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, Niwọn bi ẹnyin ti ṣe e fun ọmọ-ẹhin kikini kan ninu awọn arakọnrin mi wọnyi, ẹnyin ti ṣe e fun mi.

41 Nigbana ni yio si wi fun awọn ti ọwọ́ òsi rẹ̀ pe, Ẹnyin ẹni egún, ẹ lọ kuro lọdọ mi sinu inà ainipẹkun, ti a ti pèse silẹ fun Eṣu ati fun awọn angeli rẹ̀ :

42 Nitori ebi npa mi, ẹnyin ko si fi onjẹ fun mi : ongbẹ ngbẹ mi, ẹnyin ko si fi ohun mimu fun mi :

43 Emi ṣe alejò, ẹnyin kò gbà mi si ile : emi wà ni ìhoho, ẹnyin kò daṣọ bò mi : emi wà li aisan, ati ninu tubu, ẹnyin kò bojuto mi.

44 Nigbana ni nwọn o dahùn wi fun u pe, Oluwa, nigbawo li awa ri ti ebi npa ọ, tabi ti ongbẹ ngbẹ ọ, tabi ti iwọ ṣe alejò, tabi ti iwọ wà ni ìhoho, tabi li aisan, tabi ninu tubu, ti awa ko ṣe iranṣẹ fun ọ ?

45 Nigbana li on o da wọn li ohùn, wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, niwọn bi ẹnyin kò ti ṣe e fun ọmọ-ẹhin kan ninu awọn arakọnrin mi wọnyi, ẹnyin ko ti ṣe e fun mi.

46 Awọn wọnyi ni yio si kọja lọ sinu ìya ainipẹkun : ṣugbọn awọn olotitọ si ìye ainipẹkun.

Digitized by Google

## ORI 26.

O SI ṣe, nigbati Jesu pari gbogbo ọ̀rọ wọnyi, o wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe,
2 Ẹnyin mọ̀ pe lẹhin ọjọ meji ni ajọ irekọja, a o si fi Ọmọ-enia hàn fun ni, lati kàn a mọ agbelebu.
3 Nigbana li awọn olori alufa, awọn akọwe, ati awọn alàgba enia pejọ li afin olori alufa, ẹniti a npè ni Kaiafa,
4 Nwọn jọ gbìmọ bi nwọn iba ti fi ẹ̀tan mu Jesu, ki nwọn ki o pa a.
5 Ṣugbọn nwọn wipe, Ki iṣe li ọjọ ajọ, ki ariwo ki o má ba wà ninu awọn enia.
6 ¶ Nigbati Jesu wà ni Betani ni ile Simoni adẹtẹ̀.
7 Nibẹ̀ li obirin kan ti o ni orubà alabasta turari tutù iyebiye, o wá, o si ndà a si i lori, bi o ti joko tì onjẹ,
8 Ṣugbọn nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ ri i, inu wọn ru, nwọn wipe, Nitori kili a ṣe nfi eyi ṣòfo?
9 A ba sá tà turari tutù yi ni owo iyebiye, a ba si fifun awọn talakà.
10 Nigbati Jesu gbọ́, o wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi mba obirin na wi? nitori iṣẹ rere li o ṣe si mi lara.
11 Nigbagbogbo li ẹnyin sá ni talakà pẹlu nyin; ṣugbọn ẹnyin kò ni mi nigbagbogbo.
12 Nitori li eyi ti obirin yi dà turari tutù yi si mi lara, o ṣe e fun sisinku mi.
13 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Nibikibi ti a o gbé wasu ihin-rere yi ni gbogbo aiye, nibẹ̀ pẹlu li a o si ròhin eyi ti obirin yi ṣe, lati fi ṣe iranti rẹ̀.
14 ¶ Nigbana li ọkan ninu awọn mejila, ti a npè ni Judasi Iskariotu tọ̀ awọn olori alufa lọ,
15 O si wi fun wọn pe, Kili ẹnyin o fifun mi, emi o si fi i le nyin lọwọ? Nwọn ba a ṣe adehùn ọgbọ̀n owo fadaka.
16 Lati igba na lọ li o ti nwá ọ̀na lati fi i hàn.
17 ¶ Nigba ọjọ ikini ajọ aiwukara, awọn ọmọ-ẹhin Jesu tọ̀ ọ wá, nwọn si wi fun u pe, Nibo ni iwọ nfẹ ki a pèse silẹ dè ọ lati jẹ irekọja?
18 O si wipe, Ẹ wọ̀ ilu lọ si ọdọ ọkọnrin kan bayi, ẹ si wi fun u pe, Olukọni wipe, Akokò mi sunmọ etile; emi o ṣe ajọ irekọja ni ile rẹ pẹlu awọn ọmọ-ẹhin mi.
19 Awọn ọmọ-ẹhin na si ṣe gẹgẹ bi Jesu ti fi aṣẹ fun wọn; nwọn si pèse irekọja silẹ.
20 Nigbati alẹ si lẹ, o joko pẹlu awọn mejila.
21 Bi nwọn si ti njẹun, o wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, ọkan ninu nyin yio fi mi hàn.
22 Nwọn si kãnu gidigidi, olukuluku wọn bẹ̀rẹ si ibi i lẽre pe, Oluwa, emi ni bi?
23 O si dahùn wipe, Ẹniti o bá mi tọwọ bọ inu awo, on na ni yio fi mi hàn.
24 Ọmọ-enia nlọ bi a ti kọwe nipa tirẹ̀: ṣugbọn egbé ni fun ọkọnrin na, lọdọ ẹniti a gbé ti fi Ọmọ-enia hàn! iba san fun ọkọnrin na, bi o ṣepe a ko bí i.
25 Nigbana ni Judasi, ti o fi i hàn, dahùn wipe, Oluwa, emi ni bi? O si wi fun u pe, Iwọ wi i.
26 ¶ Bi nwọn si ti njẹun, Jesu mu akara, o si sure si i, o si bu u, o si fifun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, o wipe, Gbà, jẹ; eyiyi li ara mi.
27 O si mu ago, o dupẹ, o si fifun wọn, o wi pe, Gbogbo nyin ẹ mu ninu rẹ̀;
28 Nitoripe eyi li ẹ̀jẹ mi ti majẹmu titun, ti a ta silẹ fun ọ̀pọ enia fun imukuro ẹ̀ṣẹ.
29 Ṣugbọn mo wi fun nyin, lati isisiyi lọ emi ki yio mu ninu eso ajara yi mọ́, titi yio fi di ọjọ na, nigbati emi o si bá nyin mu u ni titun ni ijọba Baba mi.
30 Nigbati nwọn si kọ orin kan tan, nwọn jade lọ sori òke Olifi.
31 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, Gbogbo nyin ni yio kọsẹ̀ lara mi li oru yi: nitoriti a ti kọwe rẹ̀ pe, Emi o kọlù oluṣọagutan, a o si tú agbo agutan na ká kiri.
32 Ṣugbọn lẹhin igba ti mo ba jinde, emi o ṣaju nyin lọ si Galili.
33 Ṣugbọn Peteru dahùn o si wi fun u pe, Bi gbogbo enia tilẹ kọsẹ̀ lara rẹ, ṣugbọn emi kì yio kọsẹ̀ lai.
34 Jesu si wi fun u pe, Lõtọ ni mo wi fun ọ pe, Li oru yi ki akukọ ki o to kọ, iwọ o sẹ́ mi nigba mẹta.
35 Peteru wi fun u pe, Bi o tilẹ di ati ba ọ kú sibẹ emi kò jẹ sẹ́ ọ. Gẹgẹ bẽni gbogbo awọn ọmọ-ẹhin iyokù wi pẹlu.
36 ¶ Nigbana ni Jesu bá wọn wá si ibi kan ti a npè ni Getsemane, o si wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe, Ẹ joko nihinyi nigbati mo ba lọ igbadura lọhúnyi.
37 O si mu Peteru ati awọn ọmọ Sebede mejeji pẹlu rẹ̀, o si bẹ̀rẹ si ima kãnu, o si bẹ̀rẹ si irẹ̀ ẹ gidigidi.
38 Nigbana li o wi fun wọn pe, Ọkàn mi nkãnu gidigidi titi de ikú: ẹ duro nihinyi, ki ẹ si ma ba mi ṣọ́na.

Digitized by Google

39 O si lọ siwaju diẹ, o si dojubolẹ o si
ngbadura, wipe, Baba mi, bi o ba le ṣe, jẹ
ki ago yi ki o kọja kuro lori mi, ṣugbọn
kì má ṣe bi emi ti nfẹ, bikoṣe bi iwọ ti
fẹ.
40 O si tọ̀ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wá, o bá
wọn, nwọn nsùn, o si wi fun Peteru pe,
Kinla, ẹnyin ko le bá mi ṣọna ni wakati
kan?
41 Ẹ ma ṣọna, ki ẹ si ma gbadura, ki
ẹnyin ki o má ba bọ sinu idẹwò: lõtọ li
ẹmí nfẹ, ṣugbọn o ṣe alailera fun ara.
42 O si tún pada lọ li arinkeji, o si
ngbadura, wipe, Baba mi, bi ago yi kò ba
le ré mi kọja bikoṣepe mo mu u, ifẹ tirẹ ni
ki a ṣe.
43 O si wá, o si tun bá wọn, nwọn nsùn:
nitoriti oju wọn kun fun orun.
44 O si fi wọn silẹ, o si tún pada lọ, o si
gbadura li arinkẹta, o nsọ ọ̀rọ kanna.
45 Nigbana li o tọ̀ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
wá, o si wi fun wọn pe, Ẹ ma sùn wayi, ki
ẹnyin si ma simi: kiyesi i, wakati kù fẹfẹ,
ti a fi Ọmọ-enia le awọn ẹlẹṣẹ lọwọ.
46 Ẹ dide, ki a ma lọ: wò o, ẹniti o fi
mi hàn sunmọ ọdọ wa.
47 ¶ Bi o si ti nsọ lọwọ, wò o, Judasi,
ọkan ninu awọn mejila de, ati ọ̀pọ enia
pẹlu rẹ̀ ti awọn ti idà pẹlu ọgọ, lati ọdọ
awọn olori alufa ati awọn alàgba enia wá.
48 Ẹniti o si fi i hàn ti fi àmi fun wọn,
wipe, Ẹnikẹni ti mo ba fi ẹnu kò li ẹnu, on
na ni: ẹ mu u girigiri.
49 Lojukanna o wá sọdọ Jesu, o si wipe,
Alafia, Olukọni; o si fi ẹnu kò o li ẹnu.
50 Jesu si wi fun u pe, Ọrẹ́, nitori kini
iwọ fi wá? Nigbana ni nwọn wá, nwọn si
gbé ọwọ́ le Jesu, nwọn si mu u.
51 Si wò o, ọkan ninu awọn ti o wà pelu
Jesu nà ọwọ́ rẹ̀, o si fà idà rẹ̀ yọ, o si ṣá
ọkan ti iṣe ọmọ-ọdọ olori alufa, o si ké e li
etí sọnù.
52 Nigbana ni Jesu wi fun u pe, Fi idà
rẹ si ipò rẹ̀: nitoripe gbogbo awọn ti o mu
idà ni yio ti ipa idà ṣegbé.
53 Iwọ ṣebi emi ko le kepè Baba mi, on
iba si fun mi jù legioni angeli mejila lọ
lojukanna yi?
54 Ṣugbọn Iwe mimọ́ yio ha ti ṣe ti yio
fi ṣẹ, pe, bẹ̃ni yio ri?
55 Ni wakati na ni Jesu wi fun ijọ enia
pe, Emi li ẹnyin jade tọ̀ wá bi olè, ti ẹnyin
ti idà ati ọgọ lati mu? li ojojumọ li emi
mba nyin joko ni tempili ti emi nkọ́ nyin,
ẹnyin kò si gbé ọwọ́ le mi.
56 Ṣugbọn gbogbo eyi ṣe, ki Iwe mimọ́
awọn woli ba le ṣẹ. Nigbana ni gbogbo
awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ fi i silẹ, nwọn si sá lọ.
57 ¶ Awọn ti o si gbá Jesu mu, fà a lọ
si ile Kaiafa, olori alufa, nibiti awọn akọwe
ati awọn alàgba gbé pejọ si.
58 Ṣugbọn Peteru tọ̀ ọ lẹhin li òkere
titi fi de agbala olori alufa, o bọ́ si ile, o
si bá awọn ọmọ-ọdọ na joko lati ri opin
rẹ̀.
59 Nigbana li olori alufa, ati awọn alà-
gba, ati gbogbo ajọ igbimọ nwá ẹlẹri eke si
Jesu lati pa a;
60 Ṣugbọn nwọn ko ri ohun kan: otitọ
li ọ̀pọ ẹlẹri eke wá, ṣugbọn nwọn kò ri
ohun kan. Nikẹhin li awọn ẹlẹri eke meji
wá,
61 Nwọn wipe, Ọkọnrin yi wipe, Emi le
wó tempili Ọlọrun, emi o si kọ́ ọ ni ijọ
mẹta.
62 Olori alufa si dide, o si wi fun u pe,
Iwọ ko dahùn kan? kili eyi ti awọn wọnyi
njẹri si ọ?
63 Ṣugbọn Jesu dakẹ. Olori alufa dahùn
o si wi fun u pe, Mo fi Ọlọrun alãye fi ọ bu
pe, ki iwọ ki o sọ fun wa bi iwọ ba ṣe Kristi,
Ọmọ Ọlọrun.
64 Jesu wi fun u pe, Iwọ wi i: ṣugbọn
mo wi fun nyin, Lẹhin eyi li ẹnyin o ri
Ọmọ-enia ti yio joko li ọwọ́ ọtún agbara, ti
yio si ma ti inu awọsanma ọrun wá.
65 Nigbana li olori alufa fà aṣọ rẹ̀ ya, o
wipe, O sọ ọ̀rọ òdi si Ọlọrun; ẹlẹri kili a si
nwá? wò o, ẹnyin gbọ́ ọ̀rọ òdi si Ọlọrun
nisisiyi.
66 Ẹnyin ti rò o si? Nwọn dahùn,
wipe, O jẹbi ikú.
67 Nigbana ni nwọn tutọ́ si i loju, nwọn
kàn a lẹṣẹ́: awọn ẹlomiran fi atẹlẹ ọwọ́ wọn
gbá a loju,
68 Nwọn wipe, Sọtẹlẹ fun wa, iwọ
Kristi, tali ẹniti o nlù ọ ni?
69 ¶ Peteru joko lode li afin: nigbana
ni ọmọbirin kan tọ̀ ọ wá, o wipe, Iwọ pẹlu
wà pẹlu Jesu ti Galili.
70 Ṣugbọn o sẹ́ li oju gbogbo wọn, o
wipe, Emi kò mọ̀ ohun ti iwọ nwi.
71 Nigbati o si jade, si iloro, ọmọbirin
miran si ri i, o si wi fun awọn ti o wà nibẹ̀
pe, Ọkọnrin yi wà pẹlu Jesu ti Nasareti.
72 O si tun fi èpe sẹ́, wipe, Emi kò mọ̀
ọkọnrin na.
73 Nigbati o pẹ diẹ, awọn ti o duro nibẹ̀
tọ̀ ọ wá, nwọn wi fun Peteru pe, Lõtọ ọkan
ninu wọn ni iwọ iṣe; nitoripe ohùn rẹ fi ọ
hàn.
74 Nigbana li o bẹ̀rẹ si ibura ati si irá,

Digitized by Google

wipe, Emi kò mọ̀ ọkọnrin na. Lojukanna
akukọ si kọ.
75 Peteru si ranti ọ̀rọ ti Jesu wi fun u
pe, Ki akukọ ki o to kọ, iwọ o sẹ́ mi larin-
mẹta. O si bọ si ode, o sọkun kikorò.

ORI 27.

NIGBATI o di owurọ̀, gbogbo awọn olori
alufa ati awọn alàgba gbìmọ si Jesu
lati pa a:
2 Nigbati nwọn si dè e tan, nwọn mu u
lọ, nwọn si fi i le Pontiu Pilatu lọwọ ti iṣe
Bãlẹ.
3 ¶ Nigbana ni Judasi, ẹniti o fi i hàn,
nigbati o ri pe a dá a lẹbi, o ronupiwada, o
si mu ọgbọ̀n owo fadaka na pada wá ọdọ
awọn olori alufa ati awọn alàgba,
4 Wipe, emi ṣẹ̀ li eyiti mo fi ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀
hàn. Nwọn si wipe, Kili eyini si wa? mã
bojuto eyinì.
5 O si dà owo fadaka na silẹ ni tempili,
o si jade, o si lọ iso.
6 Awọn olori alufa si mu owo fadaka na,
nwọn si wipe, Ko tọ́ ki a fi i sinu iṣura,
nitoripe iye owo ẹ̀jẹ ni.
7 Nwọn si gbìmọ, nwọn si fi rà ilẹ amọ̀-
koko, lati ma sinkú awọn alejò ninu rẹ̀.
8 Nitorina li a ṣe npè ilẹ na ni Ilẹ ẹ̀jẹ,
titi di ọjọ oni.
9 Nigbana li eyi ti Jeremiah wolĩ sọ wá
ṣẹ, pe, Nwọn si mu ọgbọ̀n owo fadaka, iye
owo ẹniti a diyele, ẹniti awọn ọmọ Israeli
diyele;
10 Nwọn si fi rá ilẹ amọ̀koko, gẹgẹ bi
Oluwa ti làna silẹ fun mi.
11 Jesu si duro niwaju Bãlẹ: Bãlẹ si bi
i lẽre, wipe, Iwọ ha li Ọba awọn Ju? Jesu
si wi fun u pe, Iwọ wi i.
12 Nigbati a si nkà si i lọrùn lati ọwọ́
awọn olori alufa, ati awọn alàgba wá, on kò
dahùn kan.
13 Nigbana ni Pilatu wi fun u pe, Iwọ
ko gbọ́ ọ̀pọ ohun ti nwọn njẹri si ọ?
14 On kò si dá a ni gbolohun kan; tobẽ
ti ẹnu yà Bãlẹ gidigidi.
15 Nigba ajọ na, Bãlẹ a ti ma dá ondè
kan silẹ fun awọn enia, ẹnikẹni ti nwọn
ba fẹ.
16 Nwọn ni ondè buburu kan lakoko
na, ti a npè ni Barabba.
17 Nitorina nigbati nwọn pejọ, Pilatu
wi fun wọn pe, Tali ẹnyin nfẹ ki emi dá
silẹ fun nyin? Barabba, tabi Jesu ti a npè
ni Kristi?
18 O sá ti mọ̀ pe nitori ilara ni nwọn ṣe
fi i le on lọwọ.
19 ¶ Nigbati o si joko lori itẹ́ idajọ, aya
rẹ̀ ranṣẹ si i, wipe, Máṣe li ọwọ́ si ọkọnrin
olododo nì: nitori ìyà ohun pipọ ni mo jẹ
li oju àlá loni nitori rẹ̀.
20 Ṣugbọn awọn olori alufa, ati awọn
alàgba yi ijọ enia li ọkàn pada si ati bère
Barabba, ki o si pa Jesu.
21 Bãlẹ dahùn o si wi fun wọn pe, Ninu
awọn mejeji, ewo li ẹnyin fẹ ki emi dá silẹ
fun nyin? Nwọn wipe, Barabba.
22 Pilatu bi wọn pe, Kili emi o ha ṣe si
Jesu ẹniti a npè ni Kristi? Gbogbo wọn
wi pe, Ki a kàn a mọ agbelebu.
23 Bãlẹ si bère wipe, Ẽṣe, buburu kili o
ṣe? Ṣugbọn nwọn kigbe soke si i pe, Ki a
kàn a mọ agbelebu.
24 ¶ Nigbati Pilatu ri pe, on ko le bori
li ohunkohun, ṣugbọn pe a kuku sọ gbogbo
rẹ̀ di ariwo, o bu omi, o si wẹ̀ ọwọ́ rẹ̀ li oju
ijọ, o wipe, Ọrùn mi mọ́ nipa ẹ̀jẹ enia olõtọ
yi: ẹ kiyesi i.
25 Nigbana ni gbogbo enia dahùn, nwọn
si wipe, Ẹ̀jẹ rẹ̀ wà li ori wa, ati li ori awọn
ọmọ wa.
26 ¶ Nigbana li o da Barabba silẹ fun
wọn. Nigbati o si nà Jesu tan, o fà a le
wọn lọwọ lati kàn a mọ agbelebu.
27 Nigbana li awọn ọmọ-ogun Bãlẹ mu
Jesu lọ sinu gbàngan idajọ, nwọn si kó
gbogbo ẹgbẹ ọmọ-ogun tì i.
28 Nwọn si bọ́ aṣọ rẹ̀, nwọn si wọ̀ ọ li
aṣọ igunwà ododó.
29 ¶ Nwọn si wun ade ẹgún, nwọn si fi
dé e li ori, nwọn si fi ọpá iyè le e li ọwọ́
ọtún: nwọn si kunlẹ niwaju rẹ̀, nwọn nsin
i jẹ, wipe, Alafia, ọba awọn Ju.
30 Nwọn si tutọ́ si i lara, nwọn si gbà
ọpá iyè na, nwọn si fi lù u li ori.
31 Nigbati nwọn sin i jẹ tan, nwọn bọ
aṣọ igunwà na kuro lara rẹ̀, nwọn si fi aṣọ
rẹ̀ wọ̀ ọ, nwọn si mu u jade lọ lati kàn a
mọ agbelebu.
32 Bi nwọn si ti jade, nwọn ri ọkọnrin
kan ara Kirene, ti njẹ Simoni: on ni nwọn
fi agbara mu lati rù agbelebu rẹ̀.
33 Nigbati nwọn de ibi ti a npè ni Gol
gota, eyini ni, Ibi agbari,
34 ¶ Nwọn fi ọti kikan ti a dàpọ mọ
orõrò fun u lati mu: nigbati o si tọ́ ọ wò,
kò fẹ mu u.
35 Nwọn si kàn a mọ agbelebu, nwọn si
pìn aṣọ rẹ̀, nwọn si ṣẹ gègé le e: ki eyi ti
wolĩ wi ba le ṣẹ, pe, Nwọn pín aṣọ mi fun
ara wọn, aṣọ ileke mi ni nwọn ṣẹ gègé le.
36 Nwọn si joko, nwọn nṣọ ọ nibẹ̀;
37 Nwọn si fi ọ̀rau ifisùn rẹ̀ ti a kọ si

Digitized by Google

igberi rẹ̀, EYI NI JESU ỌBA AWỌN
JU.
38 Nigbana li a kàn awọn olè meji mọ
agbelebu pẹlu rẹ̀, ọkan li ọwọ́ ọtun, ati
ekeji li ọwọ́ òsi.
39 ¶ Awọn ti nkọja lọ si nfi ṣe ẹlẹyà,
nwọn si nmí ori wọn,
40 Wipe, Iwọ ti o wó tempili, ti o si kọ́
ọ ni ijọ mẹta, gbà ara rẹ là. Bi iwọ ba ṣe
Ọmọ Ọlọrun, sọkalẹ lati ori agbelebu wá.
41 Gẹgẹ bẽli awọn olori alufa pẹlu awọn
akọwe, ati awọn alàgba nfi ṣe ẹlẹya, wipe,
42 O ngbà awọn ẹlomiran là; on tika-
rarẹ̀ ni kò le gbalà. Ọba Israeli sa ni iṣe,
jẹ ki o sọkalẹ lati ori agbelebu wá nisisiyi,
awa o si gbà a gbọ́.
43 O gbẹkẹle Ọlọrun; jẹ ki o gbà a là
nisisiyi, bi o ba fẹran rẹ̀: o sá wipe, Ọmọ
Ọlọrun li emi.
44 Awọn olè ti a kàn mọ agbelebu pẹlu
rẹ̀ si nfi eyi na gún u loju bakanna.
45 Lati wakati kẹfa, ni òkunkun ṣú bò
gbogbo ilẹ titi o fi di wakati kẹsan.
46 Nigba wakati kẹsan ni Jesu si kigbe
li ohùn rara wipe, Eli, Eli, lama sabakta-
ni? eyini ni, Ọlọrun mi, Ọlorun mi, ẽṣe ti
iwọ fi kọ̀ mi silẹ?
47 Nigbati awọn kan ninu awọn ti o
duro nibẹ̀ gbọ́ eyi, nwọn wipe, Ọkọnrin yi
npè Elijah.
48 Lojukanna ọkan ninu wọn si sare, o
mu sponge, o tẹ̀ ẹ bọ̀ inu ọti kikan, o fi le
ori ọpá iye, o si fifun u mu.
49 Awọn iyokù wipe, Ẹ jọwọ rẹ̀ si, ẹ jẹ
ki a ma wò bi Elijah yio wá gbà a là.
50 ¶ Jesu si tún kigbe li ohùn rara, o
jọwọ ẹmí rẹ̀ lọwọ.
51 Si wo o, aṣọ ikele tempili fà ya ni
meji lati oke de isalẹ; ilẹ mì-titi, okuta si
sán;
52 Isà okú si ṣí silẹ; ọ̀pọ ọkú ninu awọn
ẹni mimọ́ ti o ti sùn jinde,
53 Nwọn ti inu isà okú wọn jade lẹhin
ajinde rẹ̀, nwọn si wá si ilu mimọ́, nwọn si
fi ara hàn ọ̀pọlọpọ enia.
54 Nigbati balogun ọrún, ati awọn ti o
wà pẹlu rẹ̀, ti nwọn nṣọ Jesu, ri isẹlẹ na,
ati ohun wọnni ti a ṣe, ẹ̀ru ba wọn gidigidi,
nwọn wipe, Lõtọ Ọmọ Ọlọrun li eyi iṣe.
55 Awọn obirin pipọ li o wà nibẹ̀, ti
nwọn ngbé òkere wò, awọn ti o ba Jesu ti
Galili wá, ti nwọn si nṣe iranṣẹ fun u:
56 Ninu awọn ẹniti Maria Magdalene
wà, ati Maria iya Jakọbu ati Jose, ati iya
awọn ọmọ Sebede.
57 Nigbati alẹ si lẹ, ọkọnrin kan ọlọrọ̀
ará Arimatea wá, ti a npè ni Josefu, ẹniti
on tikararẹ̀ iṣe ọmọ-ẹhin Jesu pẹlu:
58 O tọ̀ Pilatu lọ, o si tọrọ okú Jesu.
Nigbana ni Pilatu paṣẹ ki a fi okú na
fun u.
59 Josefu si gbé okú na, o si fi aṣọ ọ̀gbọ
mimọ́ dì i,
60 O si tẹ́ ẹ sinu iboji titun ti on tika-
rarẹ̀, eyi ti a wọ̀ ninu apata: o si yi okuta
nla di ẹnu-ọ̀na iboji na, o si lọ.
61 Maria Magdalene si wà nibẹ̀, ati
Maria keji, nwọn joko li apa eti iboji na.
62 ¶ Nigbati o di ọjọ keji, eyi ti o tẹ̀le
ọjọ ipalẹmọ, awọn olori alufa, ati awọn
Farisi wá pejọ lọdọ Pilatu,
63 Nwọn wipe, Alágba, awa ranti pe
ẹlẹtan nì wi nigbati o wà lãye pe, Lẹhin
ijọ mẹta, emi o jinde.
64 Nitorina paṣẹ ki a kiyesi iboji na
daju titi yio fi di ijọ kẹta, ki awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ máṣe wá li oru, nwọn a si ji i gbé
lọ, nwọn a si wi fun awọn enia pe, O jinde
kuro ninu okú: bẽni iṣina ikẹhìn yio si
buru jù ti iṣaju.
65 Pilatu wi fun wọn pe, Ẹnyin ní olu-
ṣọ: ẹ ma lọ, ẹ ṣe e daju bi ẹ ti fẹ.
66 Bẽni nwọn lọ, nwọn si ṣe iboji na
daju, nwọn fi edídi dí okuta na, nwọn si
yàn iṣọ.

## ORI 28.

LI opin ọjọ isimi, bi ilẹ ọjọ kini ọ̀sẹ ti
bẹ̀rẹ si imọ́, Maria Magdalene ati
Maria keji wá lati wò iboji.
2 Si wò o, isẹlẹ nla sẹ: nitori angeli
Oluwa ti ọrun sọkalẹ wá, o si yi okuta ku-
ro li ẹnu-ọ̀na, o si joko le e.
3 Oju rẹ̀ dabi manamana, aṣọ rẹ̀ si fún
bi ẹ̀gbọn owu:
4 Nitori ẹ̀ru rẹ̀ awọn oluṣọ si warìri,
nwọn dabi okú.
5 Angeli na si dahún, o si wi fun awọn
obirin na pe, Ẹ má bẹ̀ru: nitori emi mọ̀ pe
ẹnyin nwá Jesu, ti a ti kàn mọ agbelebu.
6 Kò si nihinyi: nitoriti o jinde gẹgẹ bi
o ti wi. Wá, ẹ wò ibi ti Oluwa dubulẹ.
7 Ẹ yara lọ sọ fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe,
o jinde kuro ninu okú; ẹ wò o, o ṣaju nyin
lọ si Galili; nibẹ̀ li ẹnyin o gbé ri i: wò o,
mo ti sọ fun nyin.
8 Nwọn si fi ibẹru pẹlu ayọ̀ nla yara lọ
kuro ni iboji; nwọn si sare lati wa ròhin
fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀.
9 ¶ Bi nwọn si ti nlọ sọ fun awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀, kiyesi i, Jesu pade wọn, o wipe,

Digitized by Google

Alafia. Nwọn si wá, nwọn si gbá a li ẹsẹ
mu, nwọn si tẹriba fun u.
10 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, Ẹ
má bẹ̀ru: ẹ lọ isọ fun awọn arakọnrin mi
pe, ki nwọn ki o lọ si Galili, nibẹ̀ ni nwọn
o gbé ri mi.
11 ¶ Njẹ bi nwọn ti nlọ, kiyesi i, awọn
kan ninu awọn oluṣọ wá si ilu, nwọn fi
gbogbo nkan wọnyi ti o ṣe hàn fun awọn
olori alufa.
12 Nigbati awọn pẹlu awọn alàgba pejọ,
ti nwọn si tún gbìmọ, nwọn fi ọ̀pọ owo fun
awọn ọmọ-ogun na,
13 Nwọn wi fun wọn pe, Ẹ wipe, Awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀ wá li oru, nwọn si ji i gbé lọ
nigbati awa sùn.
14 Bi eyi ba de etí Bãlẹ, awa o yi i li
ọkàn pada, a o si gbà nyin silẹ.
15 Bẽni nwọn gbà owo na, nwọn si ṣe
gẹgẹ bi a ti kọ́ wọn: ọ̀rọ yi si di rirò kiri
lọdọ awọn Ju titi di oni,
16 ¶ Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ mọ-
kanla jade lọ si Galili, si ori òke ti Jesu ti
sọ fun wọn.
17 Nigbati nwọn si ri i, nwọn foribalẹ
fun u: ṣugbọn awọn miran ṣiyemeji.
18 Jesu si wá, o si sọ fun wọn, wipe,
Gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a fifun
mi.
19 ¶ Nitorina ẹ lọ, ẹ ma kọ́ orilẹ-ède
gbogbo, ki ẹ si ma baptisi wọn li orukọ
Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmí Mimọ́:
20 Ki ẹ ma kọ́ wọn lati ma kiyesi ohun
gbogbo, ohunkohun ti mo ti pa li aṣẹ fun
nyin: ẹ si kiyesi i, emi wà pẹlu nyin ni-
gbagbogbo, titi o fi de opin aiye. Amin.

---

IHIN-RERE

TI

# MARKU.

## ORI 1.

IBẸRẸ Ihin rere Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun.
2 Bi a ti kọ ọ ninu iwe awọn woli,
Kiyesi i, mo rán onṣẹ mi siwaju rẹ, ẹniti
yio tún ọ̀na rẹ ṣe niwaju rẹ.
3 Ohùn ẹnikan ti nkigbe ni ijù, Ẹ tún
ọ̀na Oluwa ṣe, ẹ ṣe oju ọ̀na rẹ̀ tọ́.
4 Johannu mbaptisi ni ijù, o si nwasu
baptismu ti ironupiwada fun idariji ẹ̀ṣẹ.
5 Gbogbo Judea, ati awọn ará Jerusale-
mu jade tọ̀ ọ lọ, a si baptisi gbogbo wọn
lati ọwọ́ rẹ̀ li odò Jordani, nwọn njẹwọ ẹ̀ṣẹ
wọn.
6 A si wọ̀ Johannu li aṣọ irun ibakasiẹ,
amure awọ si wà li ẹgbẹ rẹ̀; o si njẹ eṣú ati
oyin ìgan.
7 O si nwasu, wipe, Ẹnikan ti o pọ̀ju
mi lọ mbọ̀ lẹhin mi, okùn bata ẹsẹ ẹniti
emi ko to tú:
8 Lõtọ li emi nfi omi baptisi nyin; ṣu-
gbọn on ni yio fi Ẹmí Mimọ́ baptisi nyin.
9 O si ṣe li ọjọ wọnni, Jesu jade wá lati
Nasareti ti Galili, a si baptisi rẹ̀ lati ọwọ́
Johannu li odò Jordani.
10 Lojukanna bi o si ti njade lati inu
omi wá, o ri ọrun ṣí silẹ, Ẹmi si sọkalẹ bi
àdaba, o si bà le e:
11 Ohùn kan si ti ọrun wá, wipe, iwọ ni
ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti inu mi dùn si gidi-
gidi.
12 Lojukanna Ẹmí si dari rẹ̀ si ijù.
13 O si wà li ogoji ọjọ ni ijù, a dán a
wò lati ọwọ́ Satani, o si wà pẹlu awọn
ẹranko igbẹ́; awọn angeli si nṣe iranṣẹ fun u.
14 Lẹhin igbati a fi Johannu sinu tubu
tan, Jesu lọ si Galili, o si nwasu ihin-rere
ijọba Ọlọrun,
15 O si wipe, Akokò na de, ijọba Ọlọrun
kù si dẹ̀dẹ: ẹ ronupiwada, ki ẹ si gbà ihin-
rere gbọ́.
16 Bi o ti nrìn leti adagun Galili, o ri
Simoni ati Anderu arakọnrin rẹ̀, nwọn nsọ
àwọn sinu adagun: nitoriti nwọn ṣe apẹja.
17 Jesu si wi fun wọn pe, Ẹ mã tọ̀ mi
lẹhin, emi o si sọ nyin di apẹja enia.

Digitized by Google

18 Lojukanna nwọn fi àwọn wọn silẹ,
nwọn si tọ̀ ọ lẹhin.
19 Bi o si ti rìn lọ siwaju diẹ, o ri Jakọ-
bu ọmọ Sebede, ati Johannu arakọnrin rẹ̀,
nwọn wà ninu ọkọ̀, nwọn ndí àwọn wọn.
20 Lojukanna o si pè wọn: nwọn si fi
Sebede baba wọn silẹ ninu ọkọ̀ pẹlu awọn
alagbaṣe, nwọn si tọ̀ ọ lẹhin.
21 Nwọn si lọ si Kapernaumu; lojukan-
na o si wọ̀ inu sinagogu li ọjọ isimi, o
nkọ́ni.
22 Ẹnu si yà wọn si ẹkọ́ rẹ̀: nitoriti o
nkọ́ wọn bi ẹniti o li ọlá, kò si dabí awọn
akọwe.
23 Ọkọnrin kan si wà ninu sinagogu
wọn, ẹniti o li ẹmi aimọ́; o si kigbe soke,
24 O wipe, Jọwọ wa jẹ; kini ṣe tawa
tirẹ, Jesu ara Nasareti? iwọ wá lati pa wa
run? emi mọ̀ ẹniti iwọ ṣe, Ẹni-Mimọ́
Ọlọrun.
25 Jesu si ba a wi, o wipe, Pa ẹnu rẹ mọ́,
ki o si jade kuro lara rẹ̀.
26 Nigbati ẹmi aimọ́ na si gbé e ṣanlẹ,
o ke li ohùn rara, o si jade kuro lara rẹ̀.
27 Hà si ṣe gbogbo wọn, tobẹ̃ ti nwọn
fi mbi ara wọn lẽre, wipe, Kili eyi? ẹkọ́
titun li eyi? nitoriti o fi agbara paṣẹ fun
awọn ẹmi aimọ́, nwọn si gbà tirẹ̀ gbọ́.
28 Lojukanna okikí rẹ̀ si kàn yi gbogbo
ẹkùn Galili ká.
29 Nigbati nwọn si jade kuro ninu sina-
gogu, nwọn wọ̀ ile Simoni ati Anderu, pẹlu
Jakọbu ati Johannu.
30 Iya aya Simoni si dubulẹ, o npotutù
ibà, nwọn si sọ ọ̀ran rẹ̀ fun u.
31 O si wá, o fà a lọwọ, o si gbé e dide;
lojukanna ibà na si ti fi i silẹ, o si ṣe
iranṣẹ fun wọn.
32 Nigbati o di aṣalẹ, ti õrùn wọ̀, nwọn
kó gbogbo awọn olokunrun, ati awọn ti o
li ẹmi èṣu tọ̀ ọ wá.
33 Gbogbo ara ilu si pejọ li ẹnu-ọ̀na.
34 O si ṣe awotan fun ọ̀pọ awọn ti o ni
onirũru àrun, o si lé ọ̀pọ ẹmi èṣu jade; ko
si jẹ ki awọn ẹ̀mi èṣu na ki o fọhun, nitori-
ti nwọn mọ̀ ọ.
35 O si dide li owurọ̀ ki ilẹ to mọ́, o
jade lọ si apakan li aginjù, nibẹ̀ li o si
ngbadura.
36 Ati Simoni ati awọn ti o wà pẹlu rẹ̀
ntọ̀ ọ lẹhin.
37 Nigbati nwọn si ri i, nwọn wi fun u
pe, Gbogbo enia nwá ọ.
38 O si wi fun wọn pe, Ẹ jẹ ki a lọ si
ilu miran, ki emi ki o le wasu nibẹ̀ pẹlu:
nitori eyi li emi sá ṣe wá.
39 O si nwãsu ninu sinagogu wọn lọ ni
gbogbo Galili, o si nlé awọn ẹmi èṣu jade.
40 Ọkọnrin kan ti o dẹtẹ si tọ̀ ọ wá, o
kunlẹ niwaju rẹ̀, o si mbẹ̀ ẹ, o wi fun u pe,
Bi iwọ ba fẹ, iwọ le sọ mi di mimọ́.
41 Jesu ṣãnu rẹ̀, o nà ọwọ́ rẹ̀, o fi bà a,
o si wi fun u pe, Mo fẹ, iwọ di mimọ́.
42 Bi o si ti sọ̀rọ, lojukanna ẹ̀tẹ na fi i
silẹ; o si di mimọ́.
43 O si kìlọ fun u gidigidi, lojukanna o
si rán a lọ;
44 O si wi fun u pe, Kiyesi i ki iwọ
máṣe sọ ohunkohun fun ẹnikẹni: ṣugbọn
ma ba ọ̀na rẹ lọ, fi ara rẹ hàn fun alufa, ki
o si bùn ẹ̀bun iwẹnumọ́ rẹ ti Mose ti pa
laṣẹ, ni ẹrí fun wọn.
45 Ṣugbọn o jade, o si nkokikí ọ̀ran na,
o si ntàn a kalẹ, tobẹ̃ ti Jesu kò si le wọ̀
ilu ni gbangba mọ́, o si duro li aginjù;
nwọn si tọ̀ ọ wá lati ìha gbogbo wá.

## ORI 2.

O SI tún wọ̀ Kapernaumu lọ lẹhin ijọ
melo kan; okikí si kàn yiká pe, o wà
ninu ile.
2 Lojukanna ọ̀pọ enia si pejọ, tobẹ̃ ti
aye kò si fun wọn mọ, kò si, to iwọn ẹnu-
ọ̀na: o si wasu ọ̀rọ na fun wọn.
3 Nwọn si wá sọdọ rẹ̀, nwọn gbé ẹnikan
ti o li ẹ̀gba tọ̀ ọ wá, ẹniti ẹni mẹrin gbé.
4 Nigbati nwọn kò si le sunmọ ọ nitori
ọ̀pọ enia, nwọn si ṣí àja ile nibiti o gbé
wà: nigbati nwọn si da a lu tan, nwọn sọ
akete na kalẹ lori eyiti ẹlẹgba na dubulẹ.
5 Nigbati Jesu ri igbagbọ́ wọn, o wi fun
ẹlẹgba na pe, Ọmọ, a dari ẹ̀ṣẹ rẹ jì ọ.
6 Ṣugbọn awọn kan ninu awọn akọwe
wà ti nwọn joko nibẹ̀, nwọn si ngbèro li
ọkàn wọn, wipe,
7 Ẽṣe ti ọkọnrin yi fi nsọ̀rọ buburu si
Ọlọrun bayi? tali o le dari ẹ̀ṣẹ jìni bikoṣe
Ọlọrun nikan?
8 Lojukanna bi Jesu ti woye li ọkàn rẹ̀
pe, nwọn ngbèro bẹ̃ ninu ara wọn, o wi fun
wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi nrò nkan wọnyi
ninu ọkàn nyin?
9 Ewo li o ya jù, lati wi fun ẹlẹgba na
pe, A dari ẹ̀ṣẹ rẹ jì ọ; tabi lati wipe, Dide,
si gbé akete rẹ, ki o si ma rìn?
10 Ṣugbọn ki ẹ le mọ̀ pe, Ọmọ-enia li
agbara li aiye lati dari ẹ̀ṣẹ jìni, (o wi fun
ẹlẹgba na pe.)
11 Mo wi fun ọ, Dide, gbé akete rẹ, ki
o si ma lọ ile rẹ.
12 O si dide lojukanna, o si gbé akete

Digitized by Google

na, o si jade lọ li oju gbogbo wọn ; tobẽ ti
ẹnu fi yà gbogbo wọn, nwọn si yìn Ọlọrun
logo, wipe, Awa ko ri irú eyi ri.
13 O si tún jade lọ si eti adagun ; gbo-
gbo ijọ enia si wá sọdọ rẹ̀, o si kọ́ wọn.
14 Bi o si ti nkọja lọ, o ri Lefi ọmọ
Alfeu, o joko ni bode, o si wi fun u pe, Mã
tọ̀ mi lẹhin. O si dide, o tọ̀ ọ lẹhin.
15 O si ṣe, bi o si ti joko tì onjẹ ni ile
rẹ̀, ọ̀pọ awọn agbowode ati ẹlẹṣẹ wá bá
Jesu joko pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ : nitoriti
nwọn pọ̀ gidigidi, nwọn si tọ̀ ọ lẹhin.
16 Nigbati awọn akọwe ati awọn Farisi
si ri i ti o mbá awọn agbowode ati awọn
ẹlẹṣẹ jẹun, nwọn wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
pe, Etiri ti o fi mba awọn agbowode ati
awọn ẹlẹṣẹ jẹ, ti o si mba wọn mu ?
17 Nigbati Jesu gbọ́, o wi fun wọn pe,
Awọn ti ara wọn le kò wá onişegun, bikoṣe
awọn ti ara wọn ko da : Emi ko wá lati pè
awọn olododo, bikoṣe awọn ẹlẹṣẹ si ironu-
piwada.
18 Awọn ọmọ-ẹhin Johannu, ati awọn
ọmọ-ẹhin awọn Farisi ati ma gbàwẹ : nwọn
si wá, nwọn si bi i pe, Ẽṣe ti awọn ọmọ-
ẹhin Johannu, ati awọn ọmọ-ẹhin awọn
Farisi fi ngbàwẹ, ṣugbọn awọn ọmọ-ẹhin
rẹ ko gbàwẹ ?
19 Jesu si wi fun wọn pe, Ẹnyin le mu
ki awọn ọmọ ile iyawo gbàwẹ, nigbati ọkọ
iyawo mbẹ lọdọ wọn ? niwọn igbati nwọn
ni ọkọ iyawo lọdọ wọn, nwọn kò le gbàwẹ.
20 Ṣugbọn ọjọ mbọ̀ nigbati a o gbà ọkọ
iyawo lọwọ wọn, nigbana ni nwọn o gbàwẹ
ni ijọ wọnni.
21 Ko si ẹniti irán idãsa aṣọ titun mọ
ogbologbo ẹ̀wu ; bi bẹ̃kọ eyi titun ti a fi lẹ
ẹ yio mu kuro ninu ogbologbo, eyi akisa a
si ma ya siwaju.
22 Ko si ẹniti ifi ọti-waini titun sinu
ogbologbo ìgo ; bi bẹ̃kọ ọti-waini titun a
bẹ́ ìgo na, ọti-waini a si danu, ìgo na a si
fàya ; ṣugbọn ọti-waini titun ni ã fi sinu
ìgo titun.
23 O si ṣe, bi Jesu ti nkọja lọ lãrin oko
ọkà li ọjọ isimi ; awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ bẹ̀rẹ si
ima ya ipẹ́ ọkà bi nwọn ti nlọ.
24 Awọn Farisi si wi fun u pe, Wo o, ẽṣe
ti nwọn fi nṣe eyi ti kò yẹ li ọjọ isimi ?
25 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin kò ti kà
ohun ti Dafidi ṣe, nigbati o ṣe alaini, ti ebi
si npa a, on, ati awọn ti o wà lọdọ rẹ̀ ?
26 Bi o ti wọ̀ inu ile Ọlọrun lọ li ọjọ
Abiatari olori alufa, ti o si jẹ akara ifihàn,
ti ko tọ́ fun u lati jẹ bikoṣe fun awọn alufa,
o si fifun awọn ti mbẹ lọdọ rẹ̀ pẹlu ?
27 O si wi fun wọn pe, A dá ọjọ isimi
nitori enia, a kò dá enia nitori ọjọ isimi :
28 Nitorina Ọmọ-enia li Oluwa ọjọ isimi
pẹlu.

## ORI 3.

O SI tún wọ̀ inu sinagogu lọ; ọkọnrin kan
si mbẹ nibẹ̀ ti ọwọ́ rẹ̀ kan rọ.
2 Nwọn si nṣọ ọ, bi yio mu u lara da li
ọjọ isimi ; ki nwọn ki o le fi i sùn.
3 O si wi fun ọkọnrin na ti ọwọ́ rẹ̀ rọ pe,
Dide ki o duro larin.
4 O si wi fun wọn pe, O tọ́ lati ma ṣe
rere li ọjọ isimi, tabi lati ma ṣe buburu ?
lati gbà ẹmí là, tabi lati pa a run ? nwọn si
dakẹ.
5 Nigbati o si fi ibinujẹ wò gbogbo wọn
yiká, ti inu rẹ̀ bajẹ nitori lile àiya wọn,
o wi fun ọkọnrin na pe, Nà ọwọ́ rẹ. O si
nà a : ọwọ́ rẹ̀ si pada bọ̀ sipò gẹgẹ bi ekeji.
6 Lojukanna awọn Farisi jade lọ lati ba
awọn ọmọ-ẹhin Herodu gbìmọ si i, bi awọn
iba ti ṣe pa a.
7 Ṣugbọn Jesu pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si
kuro nibẹ̀ lọ si eti adagun : ijọ enia pipọ
lati Galili ati Judea wá si tọ̀ ọ lẹhin,
8 Ati lati Jerusalemu, ati lati Idumea,
ati lati oke odò Jordani ; ati awọn ti o wà
niha Tire on Sidoni, ijọ enia pipọ, nigbati
nwọn gbọ́ ohun nla ti o ṣe, nwọn tọ̀ ọ wá.
9 O si wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe, ki
nwọn mu ọkọ̀ kekere kan duro lọdọ rẹ̀,
nitori ijọ enia, ki awọn enia ki o máṣe
bilù u.
10 Nitoriti o mu ọ̀pọ enia lara da ; tobẽ
ti nwọn mbì ara wọn lù u lati fi ọwọ́ kàn a,
iye awọn ti o li arùn.
11 Ati awọn ẹmi aimọ́, nigbati nwọn ri
i, nwọn wolẹ niwaju rẹ̀, nwọn nkigbe soke,
wipe, Iwọ li Ọmọ Ọlọrun.
12 Lojukanna o si kìlọ fun wọn pe, ki
nwọn ki o máṣe fi on hàn.
13 O si gùn ori òke lọ, o si npè ẹnikẹni
ti o fẹ sọdọ rẹ̀ : nwọn si tọ̀ ọ wá.
14 O si yàn awọn mejila, ki nwọn ki o
le ma gbé ọdọ rẹ̀, ati ki o si le ma rán wọn
lọ lati ma wasu,
15 Ati lati li agbara lati wò arunkarun
san, ati lati lé awọn ẹmi èṣu jade :
16 Simoni ẹniti o si sọ apele rẹ̀ ni Peteru ;
17 Ati Jakọbu ọmọ Sebede, ati Johannu
arakọnrin Jakọbu ; o si sọ apele wọn ni
Boanerge, eyi ti ijẹ, Awọn ọmọ ãrá :
18 Ati Anderu, ati Filippi, ati Barto-
lomeu, ati Matteu, ati Tomasi, ati Jakọbu

Digitized by Google

ọmọ Alfeu, ati Taddeu, ati Simoni ti a npè
ni Selote,
19 Ati Judasi Iskariotu, ẹniti o si fi i
hàn pẹlu: nwọn si wọ̀ ile kan lọ.
20 Ijọ enia si tún wọjọ pọ̀, ani tobẽ ti
nwọn ko tilẹ le jẹ onjẹ.
21 Nigbati awọn ibatan rẹ̀ si gbọ́ eyini,
nwọn jade lọ lati gbọwọ le e: nitoriti nwọn
wipe, Ori rẹ̀ bajẹ.
22 ¶ Awọn akọwe ti o ti Jerusalemu
sọkalẹ wá, wipe, O ni Beelsebubu, nipa
olori awọn ẹmi èṣu li o si fi nlé awọn ẹmi
èṣu jade.
23 O si pè wọn sọdọ rẹ̀, o fi owe ba wọn
sọrọ pe, Satani yio ti ṣe le lé Satani jade?
24 Bi ijọba kan ba si yàpa si ara rẹ̀,
ijọba na kì yio le duro.
25 Bi ile kan ba si yàpa si ara rẹ̀, ile na
kì yio le duro.
26 Bi Satani ba si dide si ara rẹ̀, ti o si
yàpa, on kì yio le duro, ṣugbọn yio de
opin.
27 Kò si ẹniti o le wọ̀ ile ọkọnrin ala-
gbara kan lọ, ki o si kó o li ẹrù lọ, bikoṣepe
o tète dì ọkọnrin alagbara na li okùn; ni-
gbana ni yio le kó o li ẹrù ni ile.
28 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Gbogbo ẹ̀ṣẹ
li a o dari wọn jì awọn ọmọ enia, ati gbo-
gbo isọrọ buburu si Ọlọrun nipa eyiti nwọn
o ma sọ̀rọ buburu:
29 Ṣugbọn ẹniti o ba sọ ọ̀rọ buburu si
Ẹmí Mimọ́ kì yio le ni idarijì titi lai, ṣu-
gbọn o wà ninu ewu ẹbi ainipẹkun:
30 Nitoriti nwọn wipe, O li ẹmi aimọ́.
31 ¶ Nigbana li awọn arakọnrin rẹ̀ ati
iya rẹ̀ wá, nwọn duro lode, nwọn si ranṣẹ si
i, nwọn npè e.
32 Awọn ọ̀pọ enia si joko lọdọ rẹ̀, nwọn
si wi fun u pe, Wò o, iya rẹ ati awọn ara-
kọnrin rẹ nwá ọ lode.
33 O si da wọn lohùn, wipe, Tani ni iya
mi, tabi awọn arakọnrin mi?
34 O si wò gbogbo awọn ti o joko lọdọ
rẹ̀ yiká, o si wipe, Wò iya mi ati awọn
arakọnrin mi!
35 Nitori ẹnikẹni ti o ba ṣe ifẹ Ọlọrun,
on na li arakọnrin mi, ati arabirin mi, ati
iya mi.

## ORI 4.

O SI tún bẹ̀rẹ si ikọni leti adagun: ọ̀pọ
ijọ enia si pejọ sọdọ rẹ̀, tobẽ ti o bọ́
sinu ọkọ̀ kan, o si joko ninu adagun; gbo-
gbo awọn enia si wà ni ilẹ leti adagun.
2 O si fi owe kọ́ wọn li ohun pipọ, o si
wi fun wọn ninu ẹkọ́ rẹ̀ pe,
3 Ẹ fi eti silẹ; Wò o, afọnrugbin kan
jade lọ ifọ́n irugbin;
4 O si ṣe, bi o ti nfọnrugbin, diẹ bọ́ si
ẹba ọ̀na, awọn ẹiyẹ oju ọrun si wá, nwọn si
ṣà a jẹ.
5 Diẹ si bọ́ sori ilẹ okuta, nibiti kò li
erupẹ̀ pipọ; lojukanna o si ti hù jade, ni-
toriti kò si ijinlẹ:
6 Ṣugbọn nigbati õrùn goke, o jóna;
nitoriti kò ni gbongbo, o si gbẹ.
7 Die si bọ́ sarin ẹgún, nigbati ẹgún si
dàgba soke, o fun u pa, kò si so eso.
8 Omiran si bọ́ si ilẹ rere, o si so eso
jade, ti o si pọ; o si mu eso jade wá, omi-
ran ọgbọ̀n, omiran ọgọta, omiran ọgọrun.
9 O si wi fun wọn pe, Ẹniti o ba li etí
lati fi gbọ́, ki o gbọ́.
10 Nigbati o kù on nikan, awọn ti o wà
lọdọ rẹ̀ pẹlu awọn mejila bi i lẽre idi owe
na.
11 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin li a fifun
lati mọ̀ ohun ijinlẹ ijọba Ọlọrun: ṣugbọn
fun awọn ti o wà lode, gbogbo ohun wọnyi
li a nfi owe sọ fun wọn:
12 Nitori ni riri ki nwọn ki o le ri, ki
nwọn má si kiyesi; ati ni gbigbọ́ ki nwọn
ki o le gbọ́, ki o má si yé wọn; ki nwọn
ki o má ba yipada, ki a ma bà dari jì wọn.
13 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin kò mọ̀
owe yi? ẹnyin o ha ti ṣe le mọ̀ owe gbogbo?
14 ¶ Afọnrugbin fọn irugbin ọ̀rọ na.
15 Awọn wọnyi si ni ti ẹba ọ̀na, nibiti
a fọn irugbin ọ̀rọ na; nigbati nwọn si ti
gbọ́, lojukanna Satani wá, o si mu ọ̀rọ na ti
a fọn si àiya wọn kuro.
16 Awọn wọnyi pẹlu si li awọn ti a fọn
sori ilẹ okuta; awọn ẹniti nigbati nwọn ba
si ti gbọ́ ọ̀rọ na, lojukanna nwọn a fi ayọ̀
gbà a;
17 Nwọn kò si ni gbongbo ninu ara wọn,
ṣugbọn nwọn a wà fun ìgba diẹ: nikẹhin
nigbati wahalà tabi inunibini ba dide nitori
ọ̀rọ na, lojukanna nwọn a kọsẹ̀.
18 Awọn wọnyi si li eyi ti a fọn sarin
ẹgún; irú awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ na,
19 Aniyan aiye yi, ati itanjẹ ọrọ̀, ati
ifẹkufẹ ohun miran bọ sinu rẹ̀, nwọn fun
ọ̀rọ na pa, bẽli o si jẹ alaili eso.
20 Awọn wọnyi si li eyi ti a fọn si ilẹ
rere; irú awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ na, ti o si gbà
a, ti o si so eso, omiran ọgbọgbọ̀n, omiran
ọgọtọta, omiran ọgọrọrun.
21 ¶ O si wi fun wọn pe, A ha le gbé
fitilà wá lati fi sabẹ ọ̀ṣuwọn, tabi labẹ ake-
te, laigbé e kà ori ọpá fitilà bi?
22 Nitori kò si ohun ti o lumọ́ ti a kì

Digitized by Google

yio fi hàn ; bẽni kò si ohun ti o pamọ́, bi-
koṣepe ki o le yọ si gbangba.
23 Bi ẹnikẹni ba li etí lati fi gbọ́, ki o
gbọ́.
24 O si wi fun wọn pe, Ẹ ma kiyesi ohun
ti ẹnyin ngbọ́: irù òṣuwọn ti ẹnyin ba fi
wọ̀n, on li a o si fi wọ̀n fun nyin : ati ẹnyin
ti ngbọ́ li a o si ma fifun pọ̀ju.
25 Nitori ẹniti o ba ni, on li a o fifun :
ati ẹniti kò ba si ni, lọwọ rẹ̀ li a o si gbà
eyi na ti o ni.
26 ¶ O si wi fun wọn pe, Bẽ sá ni ijọba
Ọlọrun, o dabi ẹnipe ki ọkọnrin kan fọn
irugbin si ilẹ ;
27 Ki o si sùn, ki o si dide li oru ati li
ọsán, ki irugbin na ki o si sọ jade ki o si
dàgba soke, on kò si mọ̀ bi o ti ri.
28 Nitori ilẹ ama so eso jade fun ara rẹ̀ ;
ekini ni ẽhù, lẹhin igba na ni ipẹ́, lẹhin
eyini ikunmọ ọkà ninu ipẹ́.
29 Ṣugbọn nigbati eso ba pọ́n tan, loju-
kanna on a tẹ̀ doje bọ inu rẹ̀, nitoriti igba
ikorè de.
30 ¶ O si wipe, Kini ijọba Ọlọrun jọ ?
tabi irú akawe wo li a ba si fi ma ṣe akawe
rẹ̀ ?
31 O dabi wóro irugbin eweko mustardi,
eyiti, nigbati a sọ ọ silẹ, ti o kére jù gbo-
gbo irugbin ti o wà ni ilẹ lọ ;
32 Ṣugbọn nigbati a fọn ọ tan, o dàgba
soke, o si di titobi jù gbogbo ewebẹ lọ, o
si pa ẹká nla ; ki awọn ẹiyẹ oju ọrun ba le
ma gbé abẹ iboji rẹ̀.
33 Irù ọ̀pọ owe bẽ li o fi mba wọn nsọ̀rọ,
niwọn bi nwọn ti le gbà a si.
34 Ṣugbọn on kì iba wọn sọrọ bikoṣe
nipa owe : nigbati o ba si kù awọn nikan,
on a si sọ idi ohun gbogbo fun awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀.
35 Ni ijọ kanna, nigbati alẹ lẹ tan, o
wi fun wọn pe, Ẹ jẹ ki a rekọja lọ si apá
keji.
36 Nigbati nwọn si ti rán ijọ enia lọ,
nwọn si gbà a gẹgẹ bi o ti wà sinu ọkọ̀.
Awọn ọkọ̀ kekere miran pẹlu si wà lọdọ rẹ̀.
37 Afẹfẹ nla si dide, riru omi si fẹ sinu
ọkọ̀, tobẽ ti o si fi kún.
38 On si wà ni idi ọkọ̀, o nsùn lori irọri :
nwọn si jí i, nwọn si wi fun u pe, Ọlukọni,
iwọ ko ṣaniyàn pe awa ṣegbé ?
39 O si dide, o ba afẹfẹ na wi, o si wi
fun adagun pe, Dakẹ· jẹ. Afẹfẹ si da,
idakẹ-rọrọ nla si de.
40 O si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi
nṣe ojo bẽ ? ẽtiṣe ti ẹnyin ko fi ni igbagbọ́ ?
41 Ẹru si ba wọn gidigidi, nwọn si nwi
fun ara wọn pe, Irú ọkọnrin kili eyi, ẽniti
afẹfẹ ati omi adagun gbà tirẹ gbọ́ ?

## ORI 5.

NWỌN si wá si apa keji adagun, ni ilẹ
awọn ara Gadara.
2 Nigbati o si nti inu ọkọ̀ jade lọ, loju-
kanna ọkọnrin ti o li ẹmi aimọ kan pade
rẹ̀, ti nti ibi ibojì jade wá,
3 Ẹniti o ni ibugbe rẹ̀ ninu ibojì ; kò si
si ẹniti o le dè e, kò si, kì iṣe ẹ̀wọn :
4 Nitoripe nigbakugba li a ti nfi ṣẹkẹ-
ṣẹkẹ ati ẹ̀wọn dè e, on a si dá ẹ̀wọn na
meji, a si dá ṣẹkẹṣẹkẹ wẹ́rẹ : bẽni kò si
ẹniti o le tù u loju.
5 Ati nigbagbogbo, li ọsán ati li oru, o
wà lori òke nla, ati ninu ibojì, a ma kigbe,
a si ma fi okuta pa ara rẹ̀ lara.
6 Ṣugbọn nigbati o ri Jesu li òkere, o
sare wá, o si foribalẹ fun u,
7 O si nkigbe li ohùn rara, wipe, Kini
ṣe temi tirẹ, Jesu, iwọ Ọmọ Ọlọrun Ọgá-
ogo ? mo fi Ọlọrun fi ọ bú, ki iwọ ki o máṣe
da mi loró.
8 Nitoriti o wi fun u pe, Jade kuro lara
ọkọnrin na, iwọ ẹmi aimọ́.
9 O si bi i lẽre pe, Orukọ rẹ ? O si da-
hùn, wipe, Legioni li orukọ mi jẹ : nitori
awa pọ̀.
10 O si bẹ̀ ẹ gidigidi pe, ki o máṣe rán
wọn jade kuro ni ilu na.
11 Agbo ọ̀pọ ẹlẹdẹ kan si wà nibẹ ti njẹ
lẹba oke.
12 Gbogbo awọn ẹmi èṣu bẹ̀ ẹ, wipe, Rán
wa lọ sinu awọn ẹlẹdẹ, ki awa ki o le wọ̀
inu wọn lọ.
13 Lọgan Jesu si jọwọ wọn. Awọn ẹmi
aimọ́ si jade, nwọn si wọ̀ inu awọn ẹledẹ lọ :
agbo ẹlẹdẹ si tupũ o si sure lọ si ibi bèbe
sinu adagun (nwọn si to ìwọn ẹgbã ;) a si
fún wọn pa ninu adagun.
14 Awọn ti mbọ́ wọn si sá, nwọn si lọ,
nwọn ròhin ni ilu nla, ati ni ilẹ na. Nwọn
si jade lọ lati wò ohun na ti o ṣe.
15 Nwọn si wá sọdọ Jesu, nwọn si ri
ẹniti o ti li ẹmi èṣu, ti o si ni Legioni na, o
joko, o si wọṣọ, iyè rẹ̀ si bọ si ipò : ẹ̀ru si
ba wọn.
16 Awọn ti o ri i si ròhin fun wọn bi o
ti ri fun ẹniti o li ẹmi èṣu, ati ti awọn ẹlẹ-
dẹ pẹlu.
17 Nwọn si bẹ̀rẹ si ibẹ̀ ẹ, wipe, ki o lọ
kuro li àgbegbe wọn.
18 Nigbati o si wọ̀ inu ọkọ̀, ẹniti o ti li
ẹmi èṣu na bẹ̀ ẹ, ki on ki o le ma bá a gbé.
19 Ṣugbọn Jesu kò gbà fun u, ṣugbọn o

Digitized by Google

wi fun u pe, Lọ si ile rẹ ki o si sọ fun awọn
ará ile rẹ, bi Oluwa ti ṣe ohun nla fun ọ,
ati bi o si ti fi iyọnu rẹ̀ hàn ọ.
20 O si pada lọ, o bẹ̀rẹ si ima ròhin ni
Dekapoli, ohun nla ti Jesu ṣe fun u: ẹnu
si yà gbogbo enia.
21 Nigbati Jesu si tun ti inu ọkọ̀ kọja si
apa keji, ọ̀pọ enia pejọ tì i: o si sunmọ
eti adagun.
22 Si kiyesi i, ọkan ninu awọn olori
sinagogu wá sọdọ rẹ̀, ti a npè ni Jairu;
nigbati o si ri i, o wolẹ lẹba ẹsẹ rẹ̀,
23 O si bẹ̀ ẹ gidigidi, wipe, Ọmọbirin mi
kekere wà loju ikú: mo bẹ̀ ọ ki o wá fi
ọwọ́ rẹ le e, ki a le mu u lara da; on o si
yè.
24 Jesu si mba a lọ; ọ̀pọ enia si ntọ̀ ọ
lẹhin, nwọn si nhá a li àye.
25 Obirin kan ti o ti li arun ọ̀rin ẹ̀jẹ li
ọdún mejila,
26 Ẹniti oju rẹ̀ si ri ohun pipọ lọdọ ọ̀pọ
awọn oniṣegun, ti o si ti ná ohun gbogbo
ti o ni tan, ti kò si sàn rara, ṣugbọn kàka
bẽ o npọ̀ siwaju.
27 Nigbati o gburo Jesu, o wá lẹhin rẹ̀
larin ìbilu awọn enia, o fi ọwọ́ kàn aṣọ rẹ̀.
28 Nitori o wipe, Bi emi ba sá le fi ọwọ́
mi kàn aṣọ rẹ̀, ara mi yio da.
29 Lọgan ni isun ẹ̀jẹ rẹ̀ si ti gbẹ; on si
mọ̀ lara rẹ̀ pe, a mu on lara da ninu arun
na.
30 Lọgan Jesu si ti mọ̀ ninu ara rẹ̀ pe,
aṣẹ ti ara on jade, o yipada larin ìbilu enia,
o si wipe, Tali o fi ọwọ́ kàn mi li aṣọ?
31 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wi fun u pe, Iwọ
ri bi ijọ enia ti nhá ọ li àye, iwọ si nwipe,
Tali o fi ọwọ́ tọ́ mi?
32 O si wò yiká lati ri ẹniti o ṣe nkan
yi.
33 Ṣugbọn obirin na ni ibẹ̀ru ati iwariri,
bi o ti mọ̀ ohun ti a ṣe lara on, o wá, o si
wolẹ niwaju rẹ̀, o si sọ gbogbo otitọ fun u.
34 O si wi fun u pe, Ọmọbirin, igbagbọ́
rẹ mu ọ lara da; ma lọ li alafia, ki iwọ ki
o si ni dida ara ninu arun rẹ.
35 Bi o si ti nsọ̀rọ li ẹnu, awọn kan ti
ile olori sinagogu wá ti o wipe, Ọmọbirin
rẹ kú: ẽṣe ti iwọ si fi nyọ olukọni lẹnu
mọ́?
36 Lojukanna bi Jesu ti gbọ́ ọ̀rọ na ti a
sọ, o si wi fun olori sinagogu na pe, Má
bẹ̀ru, sá gbagbọ́ nikan.
37 Kò si jẹ ki ẹnikẹni tọ̀ on lẹhin, bi-
koṣe Peteru, ati Jakobu, ati Johannu ara-
kọnrin Jakọbu.
38 O si wá si ile olori sinagogu, o si ri
ariwo, ati awọn ti nsọkun ti nwọn si npo-
hunrere ẹkún gidigidi.
39 Nigbati o si wọle, o wi fun wọn pe,
Ẽṣe ti ẹnyin fi npariwo bayi, ti ẹ si nsọ-
kun? ọmọbirin na ko kú, ṣugbọn sisùn li o
sùn.
40 Nwọn si fi i ṣẹ̀fẹ. Ṣugbọn nigbati o
si tì gbogbo wọn jade, o mu baba ati iya
ọmọbirin na, ati awọn ti o wà pẹlu rẹ̀, o si
wọ̀ ibi ti ọmọbirin na gbé dubulẹ si.
41 O si mu ọmọbirin na li ọwọ́, o wi fun
u pe, Talita kumi; itumọ eyi ti ijẹ Ọmọ-
birin, mo wi fun ọ, dide.
42 Lọgan ọmọbirin na si dide, o si nrìn;
nitori o to ọmọ ìwọn ọdún mejila. Ẹru si
ba wọn, ẹnu si yà wọn gidigidi.
43 Lojukanna o paṣẹ fun wọn pe, ki
ẹnikẹni ki o máṣe mọ̀; o si wipe, ki nwọn
ki o fun u li onjẹ.

## ORI 6.

O SI jade nibẹ̀, o wá si ilu baba rẹ̀; awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀ si tọ̀ ọ lẹhin.
2 Nigbati o si di ọjọ isimi, o bẹ̀rẹ si
ikọni ninu sinagogu; ẹnu si yà awọn enia
pipọ ti o gbọ́, nwọn wipe, Nibo li ọkọnrin
yi gbé ti ri nkan wọnyi? irú ọgbọ́n kili eyi
ti a fifun u, ti irú iṣẹ agbara bayi nti ọwọ́
rẹ̀ ṣe?
3 Gbẹnagbẹna kọ eyi, ọmọ Maria, ara-
kọnrin Jakọbu, ati Jose, ati ti Juda, ati
Simoni? awọn arabirin rẹ̀ ko ha wà ni-
hinyi pẹlu wa? Bẽni nwọn si kọsẹ̀ lara
rẹ̀.
4 Ṣugbọn Jesu wi fun wọn pe, Ko si
woli ti o wà laili ọlá, bikoṣe ni ilu on tika-
rarẹ̀, ati larin awọn ibatan rẹ̀, ati ninu ile
rẹ̀.
5 On ko si le ṣe iṣẹ agbara nibẹ̀, jù ti pe
o gbé ọwọ́ rẹ̀ le awọn olokunrun enia diẹ, o
si mu wọn lara da.
6 Ẹnu si yà a gidigidi nitori aigba-
gbọ́ wọn. O si lọ si gbogbo iletò yiká o
nkọni.
7 ¶ O si pè awọn mejila na sọdọ rẹ̀, o
bẹ̀rẹ si irán wọn lọ ni meji-meji; o si fi
agbara fun wọn lori awọn ẹmi aimọ́;
8 O si paṣẹ fun wọn pe, ki nwọn ki o
máṣe mu ohunkohun lọ si àjo wọn, bikoṣe
kìki ọpá ipo nikan; ki nwọn ki o máṣe mu
birigami, tabi akara, bẽni ki iṣe owo ninu
asuwọn wọn:
9 Ṣugbọn ki nwọn ki o wọ̀ salubàta wọn;
ki nwọn máṣe wọ̀ ẹ̀wu meji.
10 O si wi fun wọn pe, Nibikibi ti ẹnyin

Digitized by Google

ba wọ̀ ile kan, nibẹ̀ ni ki ẹ ma gbé titi
ẹnyin o fi jade kuro nibẹ̀ na.
11 Ẹnikẹni ti kò ba si gbà nyin, ti kò
si gbọrọ̀ nyin, nigbati ẹnyin ba jade kuro
nibẹ̀, ẹ gbọ̀n ekuru ẹsẹ nyin fun ẹrí si wọn.
Lõtọ ni mo wi fun nyin, yio san fun Sodo-
mu ati Gomorra li ọjọ idajọ jù fun ilu nla
na lọ.
12 Nwọn si jade lọ, nwọn si wasu ki
awọn enia ki o le ronupiwada.
13 Nwọn si lé ọ̀pọ awọn ẹmi èṣu jade,
nwọn si fi oróro kùn ọ̀pọ awọn ti ara wọn
ṣe alaida, nwọn si mu wọn lara da.
14 Herodu ọba si gburo rẹ̀; (nitoriti
okikí orukọ rẹ̀ kàn yiká:) o si wipe,
Johannu Baptisti jinde kuro ninu oku,
nitorina ni iṣẹ agbara hàn lara rẹ̀.
15 Awọn ẹlomiran wipe, Elijah ni. Ṣu-
gbọn awọn miran wipe, Woli kan ni, tabi
bi ọkan ninu awọn woli.
16 Ṣugbọn nigbati Herodu gbọ́, o wipe,
Johannu ni, ẹniti mo ti bẹ́ lori: on li o
jinde kuro ninu okú.
17 Herodu tikararẹ̀ sá ti ranṣẹ mu
Johannu, o si dè e sinu tubu nitori Hero-
dia, aya Filippi arakọnrin rẹ̀: on sá ti fi i
ṣe aya.
18 Johannu sá ti wi fun Herodu pe, kò
tọ́ fun iwọ lati ni aya arakọnrin rẹ.
19 Nitorina ni Herodia ṣe ni i sinu, on
si nfẹ ipa a; ṣugbọn kò le ṣe e:
20 Nitori Herodu bẹ̀ru Johannu, o si mọ̀
ọ li olõtọ enia ati ẹni mimọ́, o si pa a mọ́;
nigbati o gbọrọ rẹ̀, o ṣe ohun pipọ, o si fi
ayọ̀ gbọrọ rẹ̀.
21 Nigbati ọjọ ti o wọ̀ si de, ti Herodu
sàse ọjọ ibí rẹ̀ fun awọn ijoye rẹ̀, awọn olori
ogun nla, ati awọn alàgba Galili;
22 Nigbati ọmọbirin Herodia si wọle, ti
o si njó, inu Herodu si dùn ati awọn ti o
ba a joko pẹlu, ọba si wi fun ọmọbirin na
pe, Bère ohunkohun ti iwọ fẹ lọwọ mi, emi
o si fifun ọ.
23 O si bura fun u, wipe, Ohunkohun ti
iwọ ba bére lọwọ mi, emi o si fifun ọ, titi
fi de idameji ijọba mi.
24 O si jade lọ, o wi fun iya rẹ̀ pe, Kili
emi o bère? On si wi fun u pe, Ori
Johannu Baptisti.
25 Lojukanna, o si wọle tọ̀ ọba wá kán-
kan, o bère, wipe, nigbati o ba ṣe, emi nfẹ
ki iwọ ki o fi ori Johannu Baptisti fun mi
ninu awopọkọ.
26 Inu ọba si bajẹ gidigidi; ṣugbọn ni-
tori ibura rẹ̀, ati nitori awọn ti o bá a joko
pọ̀, kò si fẹ ikọ̀ fun u.
27 Lọgan ọba si rán iṣọ́ kan, o fi aṣẹ fun
u pe, ki a gbé ori rẹ̀ wá: o si lọ o bẹ́
Johannu lori ninu tubu.
28 A si gbé ori rẹ̀ wá ninu awopọkọ, a
si fifun ọmọbirin na: ọmọbirin na si fifun
iya rẹ̀.
29 Nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si gbọ́,
nwọn wá, nwọn gbé okú rẹ̀, nwọn si lọ tẹ́
ẹ sinu iboji.
30 Awọn aposteli si kó ara wọn jọ sọdọ
Jesu, nwọn si ròhin ohun gbogbo fun u, ti
nwọn ti ṣe, ati bi nwọn ti kọni.
31 O si wi fun wọn pe, Ẹ wá ẹnyin ti-
kara nyin si ibi ijù li apakan, ki ẹnyin ki
o simi diẹ: nitori ọ̀pọlọpọ li awọn ti mbọ̀
ti nwọn si nlọ, nwọn kò tilẹ ri àye tobẹ̃ ti
nwọn iba fi jẹun.
32 Nwọn si ba ti ọkọ̀ lọ si ibi ijù kan ni
ìkọkọ.
33 Awọn enia si ri wọn nigbati nwọn
nlọ, awọn ọpọlọpọ si mọ̀ ọ, nwọn si sare
ba ti ẹsẹ lọ sibẹ̀ lati ilu nla gbogbo wá,
nwọn si ṣiwaju wọn, nwọn si jùmọ wá sọdọ
rẹ̀.
34 Ati Jesu, nigbati o ti inu ọkọ̀ jade,
o ri ọ̀pọlọpọ enia, inu rẹ̀ si yọ́ si wọn,
nitoriti nwọn dabi awọn agutan ti kò li
oluṣọ: o si bẹ̀rẹ si ima kọ́ wọn li ohun pipọ.
35 Nigbati ọjọ si ti kọja lọ tan, awọn
ọmọ ẹhin rẹ̀ tọ̀ ọ wá, wipe, Nibi ijù li eyi,
ọjọ si kọja tan:
36 Rán wọn lọ, ki nwọn ki o le lọ si
àgbegbe ilu, ati si iletò ti o yiká, ki nwọn
ki o le rà onjẹ fun ara wọn: nitoriti nwọn
kò li ohun ti nwọn o jẹ.
37 O dahùn o si wi fun wọn pe, Ẹ fi
onjẹ fun wọn jẹ. Nwọn si wi fun u pe,
Awa o ha lọ irà igba owo idẹ akara ki a si
fifun wọn jẹ?
38 O si wi fun wọn pe, Iṣu akara melo
li ẹnyin ni? ẹ lọ wò o. Nigbati nwọn si
mọ̀, nwọn wipe, Marun, pẹlu ẹja meji.
39 O si wi fun wọn pe, ki nwọn ki o mu
gbogbo wọn joko li ẹgbẹgbẹ lori koriko
tutù.
40 Nwọn si joko li ẹgbẹgbẹ li ọrọrun ati
li aradọta.
41 Nigbati o si mu iṣu akara marun ati
ẹja meji na, o gbé oju soke, o si sure, o si
bù iṣu akara na, o si fifun awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀, ki nwọn ki o gbé e kalẹ niwaju wọn;
ati awọn ẹja meji na li o si pín fun gbogbo
wọn.
42 Gbogbo wọn si jẹ, nwọn si yó.
43 Nwọn si kó agbọ̀n mejila kún fun
ajẹkù, ati ti ẹja pẹlu.

Digitized by Google

44 Awọn ti o si jẹ iṣu akara na to ìwọn
ẹgbẹdọgbọn ọkọnrin.
45 Lojukanna li o si rọ̀ awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀ bọ sinu ọkọ̀, ki nwọn ki o si ṣiwaju lọ si
apa keji si Betsaida, nigbati o tú awọn
enia ká.
46 Nigbati o si rán wọn lọ tan, o si gùn
ori òke lọ lati gbadura.
47 Nigbati alẹ si lẹ, ọkọ̀ si wà larin
adagun, on nikan si wà ni ilẹ.
48 O si ri nwọn nṣiṣẹ ni wiwà ọkọ̀;
nitoriti afẹfẹ ṣe ọwọ òdi si wọn: nigbati
o si di ìwọn iṣọ kẹrin òru, o tọ̀ wọn wá,
o nrìn loju omi adagun, on si nfẹ ré wọn
kọja.
49 Ṣugbọn nigbati nwọn ri ti o nrìn
loju omi, nwọn ṣebi iwin ni, nwọn si kigbe
soke:
50 Nitori gbogbo wọn li o ri i, ti ẹ̀ru si
ba wọn. Lojukanna o si ba wọn sọ̀rọ, o
wi fun wọn pe, Ẹ túju̇ka: Emi ni; ẹ má
bẹ̀ru.
51 O si goke tọ̀ wọn lọ sinu ọkọ̀; afẹfẹ
si da: ẹ̀ru si ba wọn rekọja gidigidi ninu
ara wọn, ẹnu si yà wọn.
52 Nwọn kò sá ronu iṣẹ iyanu ti iṣu
akara: nitoriti ọkàn wọn le.
53 Nigbati nwọn si rekọja tan, nwọn de
ilẹ awọn ara Genesareti, nwọn si sunmọ eti
ilẹ.
54 Bi nwọn si ti njade lati inu ọkọ̀ wá,
lojukanna nwọn si mọ̀ ọ,
55 Nwọn si sare lọ si gbogbo igberiko
yiká, nwọn bẹ̀rẹ si ima gbé awọn ti ara
wọn ṣe alaida wá lori akete, si ibiti nwọn
gbé gbọ́ pe o wà.
56 Nibikibi ti o ba si gbé wọ̀, ni iletò
gbogbo, tabi ilu nla, tabi ilẹ, nwọn ngbé
olokunrun kalẹ ni igboro, nwọn si bẹ̀ ẹ pe,
ki nwọn ki o sá le fi ọwọ́ kàn iṣẹti aṣọ rẹ̀:
ìwọn gbogbo awọn ti o si fi ọwọ́ kàn a, di
dida ara ṣáṣá.

## ORI 7.

NIGBANA li awọn Farisi pejọ sọdọ rẹ̀,
ati awọn ọkan ninu awọn akọwe ti
nwọn ti Jerusalemu wá.
2 Nigbati nwọn ri omiran ninu awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀ njẹun li aimọ́, eyini ni li aiwẹ̀
ọwọ́, nwọn si mba wọn wijọ.
3 Nitori awọn Farisi, ati gbogbo awọn
Ju, bi nwọn ko ba wẹ̀ ọwọ́ wọn gidigidi,
nwọn ki ijẹun, nitoriti nwọn npa ofin
atọwọdọwọ awọn alàgba mọ́.
4 Nigbati nwọn ba si ti ọjà bọ̀, bi nwọn
ko ba wẹ̀, nwọn ki ijẹun, ati ọ̀pọlọpọ ohun
miran li o wà, ti nwọn ti gbà lati ma fiyesi,
bi wiwẹ̀ ago, ati ikòko, ati ohunèlo idẹ, ati
akete.
5 Nigbana li awọn Farisi ati awọn akọwe
bi i lẽre, wipe, Ẽṣe ti awọn ọmọ-ẹhin rẹ ko
rìn gẹgẹ bi ofin atọwọdọwọ awọn alàgba,
ṣugbọn nwọn jẹun li aiwẹ̀wọ?
6 O dahùn o si wi fun wọn pe, Otitọ ni
Isaiah sọtẹlẹ nipa ti ẹnyin agabagebe, bi a
ti kọ ọ pe, Awọn enia yi nfi ète wọn bọ̀wọ
fun mi, ṣugbọn àiya wọn jìna si mi.
7 Ṣugbọn lasan ni nwọn ntẹriba fun mi,
ti nwọn nfi ofin enia kọ́ni fun ẹkọ́.
8 Nitoriti ẹnyin fi ofin Ọlọrun si apakan,
ẹnyin nfiyesi ofin atọwọdọwọ ti enia, bi irú
wiwẹ̀ ohun-èlo ati ago: ati irú ohun miran
pipọ bẽ li ẹnyin nṣe.
9 O si wi fun wọn pe, Lõtọ li ẹnyin sọ
ofin Ọlọrun di asan, ki ẹnyin ki o le pa
ofin atọwọdọwọ ti nyin mọ́.
10 Mose sá wipe, Bọ̀wọ fun baba on iya
rẹ; ati Ẹnikẹni ti o ba fi baba tabi iya rẹ̀
bu, ẹ jẹ ki o kú ikú rẹ̀ na:
11 Ṣugbọn ẹnyin wipe, Bi enia ba wi
fun baba tabi iya rẹ̀ pe, Korbani ni, eyinì
ni pe, ẹ̀bun li ohunkohun ti iwọ iba fi jère
lara mi; o bọ́.
12 Bẹli ẹnyin ko si jẹ ki o ṣe ohunkohun
fun baba tabi iya rẹ̀ mọ́;
13 Ẹnyin nfi ofin atọwọdọwọ ti nyin, ti
ẹ fi le ilẹ, sọ ọ̀rọ Ọlọrun di asan; ati ọpọ
iru nkan bẽ li ẹnyin nṣe.
14 ¶ Nigbati o si pè gbogbo awọn enia
sọdọ rẹ̀, o wi fun wọn pe, Ẹ fi etí si mi
olukuluku nyin, ẹ si kiyesi i:
15 Kò si ohunkohun lati ode enia lọ,
nigbati o wọ̀ inu rẹ̀ ti o le sọ ọ di alaimọ́:
ṣugbọn nkan wọnni ti o ti inu rẹ̀ jade,
awọn wọnni ni isọ enia di alaimọ́.
16 Ẹniti o ba li etí lati fi gbọ́, ki o gbọ́.
17 Nigbati o si ti ọdọ awọn enia kuro
wọ̀ inu ile, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si bi i lẽre
nitori owe na.
18 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin pẹlu wà
li aimoye tobẽ? ẹnyin ko kuku kiyesi pe,
ohunkohun ti o wọ̀ inu enia lati ode lọ, ko
le sọni di alaimọ́;
19 Nitoriti ko lọ sinu ọkàn rẹ̀, ṣugbọn
sinu ara, a si yà a jade, a si gbá gbogbo
onjẹ danù?
20 O si wipe, Eyi ti o ti inu enia jade,
eyini ni isọ enia di alaimọ́.
21 Nitori lati inu, ti inu ọkàn enia ni ìro
buburu ti ijade wá, panṣaga, àgbere, ipania,
22 Olè, ojukòkoro, iwa buburu, itanjẹ,

Digitized by Google

wọbia, oju buburu, isọrọ buburu si Ọlọrun,
igberaga, iwère:
23 Lati inu wá ni gbogbo nkan buburu
wọnyi ti ijade, nwọn a si ṣọ enia di alai-
mọ́.
24 ¶ O si dide ti ibẹ̀ kuro, o si lọ si
àgbegbe Tire on Sidoni, o si wọ̀ inu ile
kan, ko si fẹ ki ẹnikẹni ki o mọ̀: ṣugbọn
on kò le fi ara pamọ́.
25 Nitori obirin kan, ẹniti ọmọbirin rẹ̀
kekere li ẹmi aimọ́ gburo rẹ̀, o wá, o si
wolẹ lẹba ẹsẹ rẹ̀:
26 Hellene si li obirin na, ara Sirofe-
nikia nipa orilẹ-ède rẹ̀; o si bẹ̀ ẹ ki on iba
lé ẹmi èṣu na jade lara ọmọbirin rẹ̀.
27 Ṣugbọn Jesu wi fun u pe, Jẹ ki a tète
fi onjẹ kún awọn ọmọ tan na: nitoriti ko
tọ́ lati mu akara ti iṣe ti awọn ọmọ, ki a fi
i fun ajá.
28 O si dahùn o si wi fun u pe, Otitọ
ni, Oluwa: ṣugbọn awọn ajá ama jẹ ẹrún
awọn ọmọ labẹ tabili.
29 O si wi fun u pe, Nitori ọ̀rọ yi ma
ba tirẹ lọ; ẹmi èṣu na ti jade kuro lara
ọmọbirin rẹ.
30 Nigbati o si pada wá si ile rẹ̀, o ri pe
ẹmi èṣu na ti jade, ọmọbirin rẹ̀ si sùn lori
akete.
31 ¶ O si tun lọ kuro àgbegbe Tire on
Sidoni, o wá si adagun Galili larin àgbegbe
Dekapoli.
32 Nwọn si mu enia kan wá sọdọ rẹ̀ ti
etí rẹ̀ di, o si yadi li ahọn rẹ̀; nwọn si bẹ̀
ẹ pe, ki o gbé ọwọ́ rẹ̀ le e.
33 O si mu u kuro larin ijọ enia lọ si
apakan, o si tẹ ika rẹ̀ bọ̀ ọ li etí, nigbati o
tutọ́, o si fi ọwọ́ tọ́ ọ li ahọn;
34 O si gbé oju soke wò ọrun, o kẹdùn,
o si wi fun u pe, Efata, eyini, ni Iwọ ṣí.
35 Lojukanna, etí rẹ̀ si ṣí, okùn ahọn rẹ̀
si tú, o si nfọhun kerekere.
36 O si kìlọ fun wọn pe, ki nwọn ki o
máṣe sọ fun ẹnikẹni: ṣugbọn bi o ti nkìlọ
fun wọn to, bẹ̃ ni nwọn si nkokikí rẹ̀ to;
37 Ẹnu si yà wọn gidigidi rekọja, nwọn
wipe, O ṣe ohun gbogbo dara: o mu aditi
gbọran, o si mu ki odi fọhun.

## ORI 8.

LI ọjọ wọnni nigbati ijọ enia pọ̀ gidigidi,
ti nwọn ko si li onjẹ, Jesu pè awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀ sọdọ rẹ̀, o si wi fun wọn pe,
2 Anu ijọ enia nṣe mi, nitoriti o di ijọ
mẹta nisisiyi ti nwọn ti wà lọdọ mi, nwọn
kò si li ohun ti nwọn o jẹ:
3 Bi emi ba si rán wọn lọ si ile wọn li
ebi, ãrẹ̀ yio mu wọn li ọ̀na: nitori awọn
pipọ li o ti ọ̀na jijìn wá.
4 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si da a lohùn wipe,
Nibo li a o gbé ti fi akara tẹ́ awọn enia yi
lọrùn li aginjù yi?
5 O si bi wọn lẽre, wipe, Iṣu akara melo
li ẹnyin ni? Nwọn si wipe, Meje.
6 O si ni ki a mu awọn enia joko ni ilẹ:
o si mu iṣu akara meje na, o sure, o bu u,
o si fifun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o
gbé e kalẹ niwaju wọn; nwọn si gbé e kalẹ
niwaju awọn enia.
7 Nwọn si li ẹja kekere diẹ: o si sure, o
si ni ki a fi wọn siwaju wọn pẹlu.
8 Bẹ̃ni nwọn jẹ, nwọn si yó: nwọn si
kó ajẹkù ti o kù jọ, agbọ̀n meje kún.
9 Awọn ti o jẹ ẹ to ìwọn ẹgbaji enia: o
si rán wọn lọ.
10 ¶ Lojukanna, o si wọ̀ ọkọ̀ pẹlu awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀, o si wá si apa ìha Dalmanuta.
11 Awọn Farisi si jade wá, nwọn bẹ̀rẹ si
ibi i lẽre, nwọn nfẹ àmi lọwọ rẹ̀ lati ọrun
wá, nwọn ndán a wò.
12 O si kẹdùn gidigidi ninu ọkàn rẹ̀, o
si wipe, Ẽṣe ti iran yi fi nwá àmi? lõtọ ni
mo wi fun nyin, Ko si àmi ti a o fifun
iran yi.
13 O si fi wọn silẹ, o si tún bọ sinu ọkọ̀
rekọja lọ si apa ekeji.
14 ¶ Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ gba-
gbé lati mu akara lọwọ, bẹ̃ni nwọn kò
si ni jù iṣu akara kan ninu ọkọ̀ pẹlu
wọn.
15 O si kìlọ fun wọn, wipe, Ẹ kiyesi
ara, ki ẹ si ma ṣọra nyin ninu iwukara
awọn Farisi ati iwukara Herodu.
16 Nwọn si mba ara wọn ṣe aroye, wipe,
Nitoriti awa kò mu akara lọwọ ni.
17 Nigbati Jesu si mọ̀, o wi fun wọn pe,
Ẽṣe ti ẹnyin fi ngbèro ninu ara nyin,
nitoriti ẹnyin ko ni akara lọwọ? ẹnyin ko
ti ikiyesi titi di isisiyi, ẹ ko si ti iwoye,
ẹnyin si li ọkàn lile titi di isisiyi?
18 Ẹnyin li oju, ẹnyin kò si riran?
ẹnyin li etí, ẹnyin kò si gbọran? ẹnyin kò
si ranti?
19 Nigbati mo bu iṣu akara marun larin
ẹgbẹdọgbọn enia, iye agbọ̀n melo kún fun
ajẹkù ti ẹnyin kójọ? Nwọn si wi fun u
pe, Mejila.
20 Ati nigba iṣu akara meje larin ẹgbaji
enia, iye agbọ̀n melo kún fun ajẹkù ti
ẹnyin kójọ? Nwọn si wipe, Meje.
21 O si wi fun wọn pe, Eha ti ṣe ti kò
fi yé nyin?

Digitized by Google

22 ¶ O si wá si Betsaida; nwọn si mu
afọju kan wá sọdọ rẹ̀, nwọn si bẹ̀ ẹ pe, ki o
fi ọwọ́ kàn a.
23 O si mu afọju na li ọwọ́, o si fà a
jade lọ sẹhin ilu; nigbati o si tutọ́ si i
loju, ti o si gbé ọwọ́ rẹ̀ le e, o bi i lẽre bi o
ri ohunkohun.
24 O si wòke, o si wipe, Mo ri awọn
enia dabi igi, nwọn nrìn.
25 Lẹhin eyini o si tún fi ọwọ́ kàn a
loju, o si mu ki o wòke: o si sàn, o si ri
gbogbo enia gbangba.
26 O si rán a pada lọ si ile rẹ̀, wipe,
Máṣe lọ si ilu, ki o má si sọ ọ fun ẹnikẹni
ni ilu.
27 ¶ Jesu si jade, ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
lọ si awọn ilu Kesarea Filippi: li ọ̀na li o
si bi awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ lẽre, nwi fun wọn
pe, Tali awọn enia nfi emi ipè?
28 Nwọn si dahùn wipe, Johannu Bap-
tisti: ṣugbọn ẹlomiran ni, Elijah ni; ati
awọn ẹlomiran wipe, Ọkan ninu awọn woli
ni.
29 O si bi wọn pe, Ṣugbọn tali ẹnyin nfi
emi pè? Peteru si dahùn o si wi fun u pe,
Iwọ ni Kristi na.
30 O si kìlọ fun wọn pe, ki nwọn ki o
máṣe sọ fun ẹnikan nitori rẹ̀.
31 O si bẹ̀rẹ si ikọ́ wọn, wipe, Ọmọ-enia
ko le ṣaima jìya ohun pipọ, a o si kọ̀ ọ lati
ọdọ awọn alàgba, ati lati ọdọ awọn olori
alufa, ati lati ọdọ awọn akọwe wá, a o si
pa a, lẹhin ijọ mẹta yio si jinde.
32 O si sọ ọ̀rọ na ni gbangba. Peteru si
mu u, o bẹ̀rẹ si iba a wi.
33 Ṣugbọn nigbati o yipada ti o wò
awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, o si ba Peteru wi pe,
Kuro lẹhin mi Satani: nitori iwọ ko rò
ohun ti iṣe ti Ọlọrun, bikoṣe eyi ti iṣe ti
enia.
34 ¶ Nigbati o si ti pè awọn enia sọdọ
rẹ̀, ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pẹlu, o wi fun
wọn pe, Ẹnikẹni ti nfẹ lati ma tọ̀ mi lẹhin,
ki o sẹ ara rẹ̀, ki o si gbé agbelebu rẹ̀, ki o
si ma tọ̀ mi lẹhin.
35 Nitori ẹnikẹni ti o ba gbà ẹmí rẹ̀ là,
yio sọ ọ nù: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba sọ ẹmí
rẹ̀ nù nitori mi ati nitori ihinrere, on na ni
yio gbà a là.
36 Nitoripe ère kini fun enia, bi o jère
gbogbo aiye, ti o si sọ ọkàn ara rẹ̀ nù?
37 Tabi kili enia iba fi ṣe paṣiparọ ọkàn
rẹ̀?
38 Nitori ẹnikẹni ti o ba tiju mi, ati ọ̀rọ
mi, ninu iran panṣaga ati ẹlẹṣẹ yi, on na
pẹlu li Ọmọ-enia yio tiju rẹ̀, nigbati o ba
mbọ̀ ninu ogo Baba rẹ̀ pẹlu awọn angeli
mimọ́.

## ORI 9.

O SI wi fun wọn pe, Lõtọ ni mo wi fun
nyin, Ẹlomiran wà ninu awọn ti o
duro nihinyi, ti kì yio ri ikú, titi nwọn o
fi ri ijọba Ọlọrun de li agbara.
2 ¶ Lẹhin ijọ mẹfa Jesu si mu Peteru,
ati Jakọbu, ati Johannu, o si mu wọn lọ
sori òke giga li apakan fun ara wọn: ara
rẹ̀ si yipada niwaju wọn.
3 Aṣọ rẹ̀ si di mimọ́, o si fun gidigidi bi
ẹ̀gbọn owu; tobẽ ti kò si aṣọ funfun ti o
le fun bi irú rẹ̀ li aiye.
4 Elijah pẹlu Mose si fi ara hàn fun
wọn: nwọn si mba Jesu sọ̀rọ.
5 Peteru si dahùn o si wi fun Jesu pe,
Baba, o dara fun wa ki awa ma gbé ihinyi:
jẹ ki awa ki o pa agọ́ mẹta; ọkan fun iwọ,
ati ọkan fun Mose, ati ọkan fun Elijah.
6 On kò sá mọ̀ eyi ti iba wi; nitori ẹ̀ru
bà wọn gidigidi.
7 Ikuku kan si wá, o ṣiji bò wọn; ohùn
kan si ti inu ikuku wá, o ni, Eyiyi li ayan-
fẹ Ọmọ mi: ẹ ma gbọ́ tirẹ̀.
8 Lojukanna, nigbati nwọn si gbé oju
soke, nwọn ko si ri ẹnikan mọ́, bikoṣe Jesu
nikan pẹlu ara wọn.
9 Bi nwọn si ti nti ori òke sọkalẹ, o kìlọ
fun wọn pe, ki nwọn ki o máṣe sọ ohun ti
nwọn ri fun ẹnikan, titi Ọmọ enia yio fi
jinde kuro ninu okú.
10 ¶ Nwọn si fi ọ̀rọ na pamọ́ sinu ara
wọn, nwọn si mbi ara wọn lẽre pe, kili
ajinde kuro ninu okú iba jẹ.
11 Nwọn si bi i lẽre, wipe, Ẽṣe ti awọn
akọwe fi wipe, Elijah ni yio tètekọ de!
12 O si dahùn o si wi fun wọn pe, Lõtọ
ni, Elijah yio tètekọ de, ti yio mu nkan
gbogbo pada si ipò; ati gẹgẹ bi a ti kọ ọ
sinu iwe nipa ti Ọmọ enia pe, ko le ṣaima
jìya ohun pipọ, ati pe a o si kọ̀ ọ silẹ.
13 Ṣugbọn mo wi fun nyin pe, Elijah ti
de na, nwọn si ti ṣe ohunkohun ti o wu
wọn si i, gẹgẹ bi a ti kọ ọ nitori rẹ̀.
14 ¶ Nigbati o si de ọdọ awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀, o si ri ijọ enia lọdọ wọn, awọn akọwe si
mbi wọn lẽre ọ̀ran.
15 Lọgan nigbati gbogbo enia si ri i, ẹnu
si yà wọn gidigidi, nwọn si sare si i, nwọn
nkí i.
16 O si bi awọn akọwe, wipe, Kili ẹnyin
mbère lọwọ wọn?
17 Ọkan ninu ijọ si dahùn, wipe, Olu-

Digitized by Google

kọni, mo mu ọmọ mi ti o ni odi ẹmi tọ̀
ọ wá ;
18 Nibikibi ti o ba gbé si mu u, a si ma
nà a tantan : on a si ma yọ ifofó li ẹnu, a
si ma pahin keke, a si ma daku ; mo si sọ
fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ, ki nwọn ba le lé e
jade ; nwọn ko si le ṣe e.
19 O si da a lohùn, o si wipe, Iran alai-
gbagbọ́ yi, emi o ti ba nyin gbé pẹ to ?
emi o si ti mu sũru fun nyin pẹ to ? mu u
wá sọdọ mi.
20 Nwọn si mu u wá sọdọ rẹ̀ : nigbati o
si ri i, lojukanna ẹmi nã nà a tàntan ; o si
ṣubu lulẹ, o si nfi ara yilẹ o si nyọ ifofò li
ẹnu.
21 O si bi baba rẹ̀ lẽre, wipe, Eti pẹ to
ti eyi ti de si i ? o si wipe, Lati igba ọmọ
kekere wá ni.
22 Nigbakugba ni ima gbé e sọ sinu iná,
ati sinu omi, lati pa a run : ṣugbọn bi iwọ
ba le ṣe ohunkohun, ṣãnu fun wa, ki o si
ràn wa lọwọ.
23 Jesu wi fun u pe, Bi iwọ ba le gba-
gbọ́, ohun gbogbo ni ṣiṣe fun ẹniti gbagbọ́.
24 Lojukanna baba ọmọ na kigbe li ohùn
rara, o si fi omije wipe, Oluwa, mo gbagbọ́;
iwọ ràn aigbagbọ́ mi lọwọ.
25 Nigbati Jesu ri ti awọn enia nsare
wọjọ pọ̀, o ba ẹmi aimọ́ na wi, o wi fun u
pe, Iwọ odi ati aditi ẹmi, mo wi fun ọ, jade
lara rẹ̀, ki iwọ máṣe wọ̀ inu rẹ̀ mọ́.
26 On si kigbe soke, o si nà a tàntàn,
o si jade lara rẹ̀ : ọmọ na si dabi ẹniti o kú;
tobẹ ti ọ̀pọ enia wipe, O kú.
27 Ṣugbọn Jesu mu u li ọwọ́, o fà a soke;
on si dide.
28 Nigbati o si wọ̀ ile, awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀ bi i lẽre nikọ̀kọ, wipe, Ēṣe ti awa ko fi
le lé e jade ?
29 O si wi fun wọn pe, Irú yi kò le jade
wá nipa ohun miran, bikoṣe nipa adura ati
àwẹ.
30 ¶ Nwọn si ti ibẹ̀ lọ kuro, nwọn si
kọja larin Galili ; on kò si fẹ ki ẹnikẹni
mọ̀.
31 Nitori o kọ́ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, o si
wi fun wọn pe, A o fi Ọmọ enia le awọn
enia lọwọ, nwọn o si pa a ; lẹhin igbati a
ba si pa a tan, yio jinde ni ijọ kẹta.
32 Ṣugbọn ọ̀rọ na kò yé wọn, ẹ̀ru si ba
wọn lati bi i lẽre.
33 ¶ O si wá si Kapernaumu : nigbati o
si wà ninu ile o bi wọn lẽre, wipe, Kili
ohun ti ẹnyin njiyàn si ninu ara nyin
nigbati ẹnyin nrìn li ọ̀na ?
34 Ṣugbọn nwọn dakẹ : nitori nigbati
nwọn nrìnbọ li ọ̀na, nwọn ti njiyàn ninu
ara wọn pe, tàli ẹniti yio papọ̀ju.
35 O si joko, o si pè awọn mejila na, o
si wi fun wọn pe, Bi ẹnikẹni ba nfẹ ṣe ẹni
iwaju, on na ni yio ṣe ẹni ikẹhin fun gbo-
gbo wọn, ati iranṣẹ gbogbo wọn.
36 O si mu ọmọ kekere kan, o gbé e
joko larin wọn ; nigbati o si gbé e li apa rẹ̀,
o wi fun wọn pe,
37 Ẹnikẹni ti o ba gbà irú ọkan ninu
awọn ọmọ kekere bayi li orukọ mi, o gbà
mi : ẹnikẹni ti o ba si gbà mi, ki iṣe emi
li o gbà, ṣugbọn o gbà ẹniti o rán mi.
38 ¶ Johannu si da a lohùn, o wipe,
Olukọni, awa ri ẹnikan o nfi orukọ rẹ lé
awọn ẹmi èṣu jade, on kò si tọ̀ wa lẹhin :
awa si da a lẹkun, nitoriti ko tọ̀ wa lẹhin :
39 Jesu si wipe, Máṣe da a lẹkun mọ́:
nitori kò si ẹnikan ti yio ṣiṣẹ aṣẹ li orukọ
mi, ti o si le yara fi ibi sisọ-kusọ si mi.
40 Nitori ẹniti ko ba lodi si wa, o wà li
apa ti wa.
41 Nitori ẹnikẹni ti o ba fi ago omi kan
fun nyin mu li orukọ mi, nitoriti ẹnyin ṣe
ti Kristi, lõtọ ni mo wi fun nyin, on kì yio
padanù ère rẹ̀.
42 Ẹnikẹni ti o ba si mu ki ọkan ninu
awọn kekeke wọnyi ti o gbà mi gbọ́ kọsẹ̀, o
ya fun u ki a so ọlọ mọ́ ọ li ọrùn, ki a si rì
i sinu omi okun.
43 Bi ọwọ́ rẹ ba mu ọ kọsẹ̀, ke e kuro :
o ya fun ọ ki o ṣe akewọ lọ si ibi ìye, jù ki
o li ọwọ mejeji ki o lọ si ọrun apadi, sinu
iná ajõku :
44 Nibiti kòkoro wọn ki ikú, ati iná na
kò si ni ikú.
45 Bi ẹsẹ rẹ ba si mu ọ kọsẹ̀, ke e kuro :
o ya fun ọ ki o ṣe akesẹ lọ si ibi ìye, jù ki
o li ẹsẹ mejeji ki a gbé ọ sọ si ọrun apadi,
sinu iná ajõku :
46 Nibiti kòkoro wọn ki ikú, ati iná na
kò si ni ikú.
47 Bi oju rẹ ba si mu ọ kọsẹ̀, yọ ọ jade :
o ya fun ọ ki o lọ si ijọba Ọlọrun li oloju-
kan, jù ki o li oju mejeji, ki a gbè ọ sọ sinu
iná ọrun apadi :
48 Nibiti kòkoro wọn ki ikú, ati iná na
kò si ni ikú.
49 Nitoripe olukuluku li a o fi iná dùn,
ati gbogbo ẹbọ li a o si mu iyọ̀ dùn.
50 Iyọ̀ sá dara : ṣugbọn bi iyọ̀ ba sọ
agbara rẹ̀ nù, nibo li ẹnyin o gbe fi i dùn ;
Ẹ ni iyọ̀ ninu ara nyin, ki ẹ si ma wà li
alafia si ẹnikeji nyin.

Digitized by Google

## ORI 10.

O SI dide kuro nibẹ̀, o si wá si ẹkùn
Judea niha oke odò Jordani: awọn
enia si tún tọ̀ ọ wá; bi iṣe rẹ̀ ti ri, o si tún
nkọ́ wọn.
2 ¶ Awọn Farisi si tọ̀ ọ wá, nwọn ndán
a wò, nwọn si bi i lẽre, wipe, O tọ́ fun
ọkọnrin ki o fi aya rẹ̀ silẹ?
3 O si dahùn o si wi fun wọn pe, Aṣẹ
kini Mose pa fun nyin?
4 Nwọn si wipe, Mose fi aṣẹ fun wa lati
kọ iwe ikọsilẹ fun u, ki a si fi i silẹ.
5 Jesu si da wọn lohùn, o si wi fun wọn
pe, Nitori lile àiya nyin li o ṣe kọ irú aṣẹ
yi fun nyin.
6 Ṣugbọn lati igba ọjọ ìwa wá, Ọlọrun
da wọn ti akọ ti abo.
7 Nitori eyi li ọkọnrin yio ṣe fi baba ati
iya rẹ̀ silẹ, on a si famọ́ aya rẹ̀;
8 Awọn mejeji a si di ara kan: nitorina
nwọn kì iṣe meji mọ́, bikoṣe ara kan.
9 Nitorina ohun ti Ọlọrun ba so ṣọkan,
ki ẹnikẹni ki o máṣe yà wọn.
10 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si tun bi i lẽre
ọ̀ran kanna ninu ile.
11 O si wi fun wọn pe, Ẹnikẹni ti o ba fi
aya rẹ̀ silẹ, ti o ba si gbé omiran ni iyawo,
o ṣe panṣaga si i.
12 Bi obirin kan ba si fi ọkọ rẹ̀ silẹ, ti a
ba si gbé e ni iyawo fun ẹlomiran, o' ṣe
panṣaga.
13 ¶ Nwọn si gbé awọn ọmọ-ọwọ tọ̀ ọ
wá, ki o le fi ọwọ́ tọ́ wọn: awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ si ba awọn ti o gbé wọn wá wi.
14 Ṣugbọn nigbati Jesu ri i, inu rẹ̀ bajẹ
gidigidi, o si wi fun wọn pe, Ẹ jẹ ki awọn
ọmọ kekere ki o wá sọdọ mi, ẹ má si ṣe da
wọn lẹkun: nitori irú wọn ni ijọba Ọlọrun.
15 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti
kò ba gbà ijọba Ọlọrun bi ọmọ kekere, kì
yio le wọ̀ inu rẹ̀.
16 O si gbé wọn li apa rẹ̀, o gbé ọwọ́ rẹ̀
le wọn, o si sure fun wọn.
17 ¶ Bi o si ti nlọ li ọ̀na, ẹnikan wá o
nsare tọ̀ ọ, o si kunlẹ fun u, o bi i lère,
wipe, Olukọni rere, kili emi o ṣe ti emi o fi
le jogún ìye ainipẹkun?
18 Jesu si wi fun u pe, Ẽṣe ti iwọ fi
npè mi li ẹni rere? ẹni rere kan ko si
bikoṣe ẹnikan, eyini li Ọlọrun.
19 Iwọ sá mọ̀ ofin. Máṣe panṣaga,
máṣe pania, máṣe jale, máṣe jẹri eke,
máṣe rẹ́ ẹni jẹ, bọwọ fun baba on iya rẹ.
20 O si dahùn o si wi fun u pe, Olu-
kọni, gbogbo nkan wọnyi li emi ti nkiyesi
lati igba ewe mi wá.
21 Nigbana ni Jesu wò o, o fẹràn rẹ̀, o
si wi fun u pe, Ohun kan li o kù fun ọ:
ba ọ̀na rẹ lọ, tà ohunkohun ti o ni, ki o si
fifun awọn talakà, iwọ o si ni iṣura li ọrun:
si wá, gbé agbelebu, ki o si mã tọ̀ mi lẹhin.
22 Inu rẹ̀ si bajẹ si ọ̀rọ nì, o si jade lọ
ni ibinujẹ: nitoriti o li ọrọ̀ pipọ.
23 ¶ Jesu si wò yiká, o si wi fun awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe, Yio ti ṣoro to fun awọn ti
o li ọrọ̀ lati wọ̀ ijọba Ọlọrun!
24 Ẹnu si yà awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si ọ̀rọ rẹ̀.
Ṣugbọn Jesu si tun dahùn wi fun wọn pe,
Ẹnyin ọmọ, yio ti ṣoro to fun awọn ti o
gbẹkẹle ọrọ̀ lati wọ̀ ijọba Ọlọrun!
25 O rọrun fun ibakasiẹ lati wọ̀ oju
abẹrẹ, jù fun ọlọrọ̀ lati wọ̀ ijọba Ọlọrun lọ.
26 Ẹnu si yà wọn rekọja, nwọn si mba
ara wọn sọ wipe, Njẹ tali o ha le là?
27 Jesu si wò wọn o wipe, Enia li eyi
ṣoro fun, ṣugbọn ki iṣe fun Ọlọrun: nitori
ohun gbogbo ni ṣiṣe fun Ọlọrun.
28 ¶ Nigbana ni Peteru bẹ̀rẹ si iwi fun
u pe, Wò o, awa ti fi gbogbo nkan silẹ,
awa si ntọ̀ ọ lẹhin.
29 Jesu si dahùn, o wipe, Lõtọ ni mo
wi fun nyin, Kò si ẹniti o fi ile silẹ, tabi
arakọnrin, tabi arabirin, tabi baba, tabi
iya, tabi aya, tabi ọmọ, tabi ilẹ, nitori mi,
ati nitori Ihin-rere,
30 Ṣugbọn nisisiyi li aiye yi on o si gbà
ọgọrọrun, ile, ati arakọnrin, ati arabirin,
ati iya, ati ọmọ, ati ilẹ, pẹlu inunibini;
ati li aiye ti mbọ̀ ìye ainipẹkun,
31 Ṣugbọn ọ̀pọ awọn ti o ṣiwaju ni yio
kẹhin; awọn ti o kẹhin ni yio si ṣiwaju.
32 ¶ Nwọn si wà li ọ̀na ngoke lọ si
Jerusalemu; Jesu si nlọ niwaju wọn: ẹnu
si yà wọn; bi nwọn si ti ntọ̀ ọ lẹhin, ẹru
ba wọn. O si tun mu awọn mejila, o bẹ̀rẹ
si isọ gbogbo ohun ti a o ṣe si i fun wọn.
33 Wipe, Sá wò o, awa ngoke lọ si Jeru-
salemu, a o si fi Ọmọ enia le awọn olori
alufa, ati awọn akọwe lọwọ; nwọn o si da
a lẹbi ikú, nwọn o si fà a le awọn Keferi
lọwọ:
34 Nwọn o si fi i ṣe ẹlẹyà, nwọn o si nà
a, nwọn o si tutọ́ si i lara, nwọn o si pa a:
ni ijọ kẹta yio si jinde.
35 ¶ Jakọbu ati Johannu awọn ọmọ
Sebede si wá sọdọ rẹ̀, wipe, Olukọni, awa
nfẹ ki iwọ ki o ṣe fun wa, ohunkohun ti
awa ba nfẹ.
36 O si bi wọn lẽre pe, Kili ẹnyin nfẹ ti
emi iba ṣe fun nyin?

Digitized by Google

37 Nwọn si wi fun u pe, Fifun wa ki
awa ki o le joko, ọkan li ọwọ́ ọtun, ati
ekeji li ọwọ́ òsi rẹ, ninu ogo rẹ.
38 Ṣugbọn Jesu wi fun wọn pe, Ẹnyin
ko mọ̀ ohun ti ẹnyin mbère: ẹnyin le mu
ninu ago ti emi o mu? ati ki a fi baptismu
ti a o fi baptisi mi baptisi fun nyin?
39 Nwọn si wi fun u pe, Awa le ṣe e.
Jesu si wi fun wọn pe, Lõtọ li ẹnyin o mu
ninu ago ti mo mu; ati ninu baptismu ti
a o fi baptisi mi li a o si fi baptisi nyin:
40 Ṣugbọn lati joko li ọwọ́ ọtún ati li
ọwọ́ òsi mi ki iṣe ti emi lati fi funni: bi-
koṣepe kìki fun awọn ẹniti a ti pèse rẹ̀ silẹ
fun.
41 Nigbati awọn mẹwa iyokù gbọ́, nwọn
bẹ̀rẹ si ibinu gidigidi si Jakọbu ati Jo-
hannu.
42 Ṣugbọn Jesu pè wọn sọdọ rẹ̀, o si wi
fun wọn pe, Ẹnyin mọ̀ pe, awọn ti a fi ṣe
olori fun awọn Keferi, ama lò agbara lori
wọn: ati awọn ẹni-nla ninu wọn ama fi
ọlá tẹri wọn ba.
43 Ṣugbọn kì yio ri bẽ ninu nyin: ṣu-
gbọn ẹnikẹni ti o ba fẹ tobi ninu nyin, on
ni yio ṣe iranṣẹ nyin:
44 Ati ẹnikẹni ninu nyin ti o ba fẹ ṣe
olori, on ni ki o ṣe ọmọ-ọdọ fun gbogbo
nyin.
45 Gẹgẹ bi Ọmọ-enia ko ti wá ki amã ṣe
iranṣẹ fun u, bikoṣe lati ma ṣe iranṣẹ
funni, ati lati fi ẹmi rẹ̀ ṣe irapada fun
ọ̀pọlọpọ enia.
46 ¶ Nwọn si wá si Jeriko: bi o si ti
njade kuro ni Jeriko pẹlu awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀, ati ọ̀pọ awọn enia, Bartimeu afọju, ọmọ
Timeu, joko lẹba ọ̀na o nṣagbe.
47 Nigbati o gbọ́ pe, Jesu ti Nasareti ni,
o bẹ̀rẹ si ikigbe lohùn rara, o wipe, Jesu,
iwọ Ọmọ Dafidi ṣãnu fun mi.
48 Awọn enia si ba a wi pe, ki o pa ẹnu
rẹ̀ mọ́: ṣugbọn on si kigbe si i jù bẽ lọ pe,
Iwọ Ọmọ Dafidi, ṣãnu fun mi.
49 Jesu si dẹṣẹ duro, o si paṣẹ pe ki a
pè e wá. Nwọn si pè ọkọnrin afọju na,
nwọn wi fun u pe, Tùjuka, dide; o npè ọ.
50 O si bọ ẹ̀wu rẹ̀ junù, o dide, o si tọ
Jesu wá.
51 Jesu si dahùn o si wi fun u pe, Kini
iwọ nfẹ ki emi ki o ṣe fun ọ? Ọkọnrin
afọju na si wi fun u pe, Oluwa, ki emi ki
o le riran.
52 Jesu si wi fun u pe, Ma ba tirẹ lọ;
igbagbọ́ rẹ mu ọ lara da. Lojukanna, o si
riran, o si tọ̀ Jesu lẹhin li ọ̀na.

ORI 11.

NIGBATI nwọn sunmọ eti Jerusalemu,
leti Betfage ati Betani, li òke Olifi, o
rán awọn meji ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀,
2 O si wi fun wọn pe, Ẹ lọ si iletò ti o
kọju si nyin: lojukanna bi ẹnyin ti nwọ̀
inu rẹ̀ lọ, ẹnyin o ri ọmọ kẹtẹkẹtẹ kan ti a
so, ti ẹnikẹni ko gùn ri; ẹ tú u, ki ẹ si fà
a wá.
3 Bi ẹnikẹni ba si wi fun nyin pe, Ẽṣe
ti ẹnyin fi nṣe eyi? ẹ wipe, Oluwa ni ifi ṣe;
lojukanna yio sí rán a wá sihinyi.
4 Nwọn si mu ọ̀na wọn pọ̀n, nwọn ri
ọmọ kẹtẹkẹtẹ na, a so o si ẹnu-ọ̀na lẹhin
ilẹkun nibiti ọ̀na meji gbé pade; nwọn si
tú u.
5 Awọn ọkan ninu awọn ti o duro nibẹ̀
wi fun wọn pe, Kili ẹnyin nṣe, ti ẹnyin fi
ntú ọmọ kẹtẹkẹtẹ nì?
6 Nwọn si wi fun wọn gẹgẹ bi Jesu ti fi
aṣẹ fun wọn: nwọn si jọwọ wọn lọwọ lọ.
7 Nwọn si fà ọmọ kẹtẹkẹtẹ na tọ̀ Jesu
wá, nwọn si tẹ́ aṣọ wọn si ẹ̀hin rẹ̀; on si
joko lori rẹ̀.
8 Awọn enia pipọ tẹ́ aṣọ wọn si ọ̀na: ati
awọn ẹlomiran ṣẹ́ ẹká igi wẹ́wẹ, nwọn si
fọn wọn si ọ̀na.
9 Awọn ti nlọ niwaju, ati awọn ti o si
ntọ̀ wọn lẹhin, nkigbe wipe, Hosanna;
Olubukun li ẹniti o mbọ̀ wá li orukọ
Oluwa:
10 Olubukun ni ijọba Dafidi, baba wa,
ti o mbọ̀ wá li orukọ Oluwa: Hosanna loke
ọrun.
11 Jesu si wọ̀ Jerusalemu, ati inu tem-
pili: nigbati o si wò ohun gbogbo yiká,
alẹ sa ti lẹ tan, o si jade lọ si Betani pẹlu
awọn mejila.
12 ¶ Ni ijọ keji, nigbati nwọn nti
Betani wá, ebi si npa a:
13 O si ri igi ọpọtọ kan li òkere ti o li
ewé, o wá, bi on iba le ri ohun kan lori
rẹ̀: nigbati o si wá si ịdi rẹ̀, kò si ri ohun
kan, bikoṣe kìki ewé; nitoriti akokò eso
ọpọtọ ko ti ito.
14 Jesu si dahùn o si wi fun u pe, Kò si
ẹnikẹni ti yio jẹ eso lori rẹ lati oni lọ titi
lailai. Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si gbọ́ ọ.
15 ¶ Nwọn si wá si Jerusalemu: Jesu
si wọ̀ inu tempili lọ, o si bẹ̀rẹ si ilé awọn
ti ntà ati awọn ti nrà ni tempili jade, o si
tari tabili awọn onipaṣiparọ owo danù, ati
ibujoko awọn ti ntà ẹiyẹle.
16 Kò si jẹ ki ẹnikẹni ki o mu ohun-
èlo kọja larin tempili.



Digitized by Google

17 O si nkọni, o nwi fun wọn pe, A kò
ti kọwe rẹ̀ pe, Ile adura fun gbogbo orilẹ-
ède li a o ma pè ile mi? ṣugbọn ẹnyin ti sọ
ọ di ihò olè.
18 Awọn akọwe ati awọn olori alufa gbọ́
ọ, nwọn si nwá ọ̀na bi nwọn iba ti ṣe pa a
run: nitori nwọn bẹ̀ru rẹ̀, nitoriti ẹnu yà
gbogbo awọn enia si ẹkọ́ rẹ̀.
19 Nigbati alẹ si lẹ, o ti ilu-nla jade
kuro.
20 ¶ O si di owurọ̀, bi nwọn si ti nre-
kọja, nwọn ri igi ọpọtọ na gbẹ lati gbongbo.
21 Peteru si wa iranti o wi fun u pe,
Oluwa, wò bi igi ọpọtọ ti iwọ fi bú ti wọwe
danù.
22 Jesu si dahùn o si wi fun wọn pe, Ẹ
ni igbagbọ́ si Ọlọrun.
23 Lõtọ ni mo sá wi fun nyin pe, Ẹni-
kẹni ti o ba wi fun òke yi pe, Iwọ ṣidi, ki
o si bọ sinu okun; ti kò ba si ṣiyemeji li
àiya rẹ̀, ṣugbọn ti o ba gbagbọ́ li àiya rẹ pe,
nkan wọnni ti on wi yio ṣẹ; yio si ni
ohunkohun ti o wi.
24 Nitorina mo wi fun nyin, Ohunkohun
ti ẹnyin fẹ, nigbati ẹnyin ba ngbadura, ẹ
gbagbọ́ pe, ẹnyin ri wọn gbà na, ẹnyin o si
ni wọn.
25 Nigbati ẹnyin ba duro ngbadura, ẹ
darijìni, bi ẹnyin ba ni ohunkohun si ẹni-
kẹni: Baba nyin ti mbẹ li ọrun yio si dari
ẹ̀ṣẹ nyin jì nyin pẹlu.
26 Ṣugbọn bi ẹnyin kò ba darijìni, Baba
nyin ti mbẹ li ọrun kì yio si dari ẹ̀ṣẹ nyin
jì nyin.
27 ¶ Nwọn ti tún pada wá si Jerusalemu:
bi o si ti nrìn ni tempili, awọn olori alufa,
ati awọn akọwe, ati awọn alàgba, tọ̀ ọ wá,
28 Nwọn si wi fun u pe, Ọlá kini iwọ fi
nṣe nkan wọnyi? tali o si fun ọ li ọlá yi
lati fi ṣe nkan wọnyi?
29 Jesu si dahùn o si wi fun wọn pe,
Emi o si bi nyin lẽre kan pẹlu, ki ẹ si da
mi lohùn, emi o si sọ fun nyin ọla ti emi fi
nṣe nkan wọnyi.
30 Baptismu ti Johannu lati ọrun li o ti
wá, tabi lọdọ enia? ẹ da mi lohùn.
31 Nwọn si ba ara wọn gbèro, wipe, Bi
awa ba wipe, Lati ọrun wá ni: on o wipe,
Ẽha ti ṣe ti ẹnyin ko fi gbà a gbọ́!
32 Ṣugbọn bi awa ba wipe, Lọdọ enia;
nwọn bẹ̀ru awọn enia: nitori gbogbo enia
kà Johannu si pe, woli ni iṣe nitõtọ.
33 Nwọn si dahùn wi fun Jesu pe, Awa
kò mọ̀. Jesu si dahùn wi fun wọn pe, Njẹ
emi kì yio si wi fun nyin ọlá ti emi fi nṣe
nkan wọnyi

## ORI 12.

O SI bẹ̀rẹ si ifi owe ba wọn sọ̀rọ pe, Ọkọn-
rin kan gbìn ọgba ajara kan, o si
sọgba yi i ká, o wà ibi ifunti waini, o kọ́
ile-iṣọ si i, o si fi ṣe agbatọju fun awọn olu-
ṣọgba, o si lọ si ilu òkere.
2 Nigbati o si di akokò, o rán ọmọ-ọdọ
rẹ̀ kan si awọn oluṣọgba na, ki o le gbà
ninu eso ọgba ajara na lọwọ awọn oluṣọ-
gba.
3 Nwọn si mu u, nwọn lù u, nwọn si
rán a pada lọwọ ofo.
4 O si tún rán ọmọ-ọdọ miran si wọn,
on ni nwọn si sọ okuta lù, nwọn ṣá a lọgbẹ́
li ori, nwọn si fi itiju lé e jade lọwọ ofo.
5 O si tún rán omiran; eyini ni nwọn si
pa, ati ọ̀pọ miran; ti nwọn nlù miran,
nwọn si npa miran.
6 Ṣugbọn o kù ọmọ rẹ̀ kan ti o ni, ti iṣe
ayanfẹ rẹ̀ gidigidi o si rán a si wọn pẹlu
nikẹhin, o wipe, Nwọn o ṣe ojusaju fun
ọmọ mi.
7 Ṣugbọn awọn oluṣọgba wọnni wi fun
ara wọn pe, Eyiyi li arole; ẹ wá, ẹ jẹ ki a
pa a, ki ogún rẹ̀ ki o le ṣe ti wa.
8 Nwọn si mu u, nwọn pa a, nwọn si wọ́
ọ jade kuro ninu ọgba ajara na.
9 Njẹ kili oluwa ọgba ajara na yio ṣe?
On o wá, yio si pa awọn oluṣọgba wọnni
run, yio si fi ọgba ajara rẹ̀ ṣe agbatọju fun
awọn ẹlomiran.
10 Ẹnyin kò ti kà Iwe mimọ́ yi; Okuta
ti awọn ọmọle kọ̀ silẹ, on na li o di pàtaki
igun ile:
11 Eyi ni iṣe Oluwa, o si jẹ iyanu li oju
wa?
12 Nwọn si nwá ọ̀na ati gbé ọwọ́ le e,
ṣugbọn nwọn bẹ̀ru awọn enia: nitori nwọn
mọ̀ pe, o pa owe na mọ wọn: nwọn si fi i
silẹ, nwọn ba ọ̀na wọn lọ.
13 ¶ Nwọn si rán awọn kan si i ninu
awọn Farisi, ati ninu awọn ọmọ-ẹhin
Herodu, lati dì i mu li ọ̀rọ rẹ̀.
14 Nigbati nwọn si de, nwọn wi fun u
pe, Olukọni, awa mọ̀ pe olotitọ ni iwọ,
bẹ̀ni iwọ kì iwoju ẹnikẹni: nitori iwọ kì
iṣe ojusaju fun enia kan, ṣugbọn iwọ nkọ́ni
li ọ̀na Ọlọrun li otitọ: O tọ́ lati ma san
owode fun Kesari, tabi kò tọ́?
15 Ki awa ki o fifun u, tabi ki a má
fifun u? Ṣugbọn Jesu mọ̀ agabagebe wọn,
o wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi ndán mi
wò? ẹ mu owode kan fun mi wá ki emi ki
o wò o.

Digitized by Google

16 Nwọn si mu u wá. O si bi wọn pe,
Aworan ati akọle tali eyi? Nwọn si wi
fun u pe, Ti Kesari ni.
17 Jesu si dahùn o si wi fun wọn pe,
Njẹ ẹ fi ohun ti iṣe ti Kesari fun Kesari,
ati ohun ti iṣe ti Ọlọrun fun Ọlọrun. Ẹnu
si yà wọn si i.
18 ¶ Nigbana li awọn Sadusi wá sọdọ
rẹ̀, awọn ti o wipe ajinde okú kò si; nwọn
si bi i lẽre, wipe,
19 Olukọni, Mose kọwe fun wa pe, Bi
arakọnrin ẹnikan ba kú, ti o ba si fi aya rẹ̀
silẹ, ti kò si fi ọmọ silẹ, ki arakọnrin rẹ̀ ki
o ṣu aya rẹ̀ lopó, ki o le bímọ si ipò ara-
kọnrin rẹ̀.
20 Njẹ awọn arakọnrin meje kan ti wà:
eyi ekini gbé aya rẹ̀ ni iyawo, o si kú lai fi
ọmọ silẹ.
21 Eyi ekeji si ṣu u lopó, on si kú, bẹ̃li
on kò si fi ọmọ silẹ: gẹgẹ bẹ̃ si li ẹkẹta.
22 Awọn mejeje si ṣu u lopó, nwọn kò
si fi ọmọ silẹ: nikẹhin gbogbo wọn obirin
na kú pẹlu.
23 Njẹ li ajinde okú, nigbati nwọn o
jinde, aya tani yio ha ṣe ninu wọn? nitori
awọn mejeje li o sá ni i li aya?
24 Jesu si dahùn o wi fun wọn pe,
Ẹnyin kò ha ṣina bayi, nitoriti ẹnyin kò
mọ̀ Iwe mimọ́, ẹ kò si mọ̀ agbara Ọlọrun?
25 Nitori nigbati nwọn o jinde kuro
ninu okú, nwọn kò ni gbeyawo, a kò si ni
fi wọn funni ni igbeyawo; ṣugbọn nwọn
dabi awọn angeli ti mbẹ li ọrun.
26 Nipa ti okú, niti pe nwọn jinde:
ẹnyin ko ti kà a ninu iwe Mose, bi Ọlọrun
ti sọ fun u ninu igbẹ́, wipe, Emi li Ọlọrun
Abrahamu, ati Ọlọrun Isaaki, ati Ọlọrun
Jakọbu?
27 On kì iṣe Ọlọrun awọn okú, bikoṣe
Ọlọrun awọn alãye: nitorina ẹnyin ṣina
gidigidi.
28 ¶ Ọkan ninu awọn akọwe de, nigbati
o si gbọ́ bi nwọn ti jùmọ mba ara wọn sọrọ
pọ̀, ti o si woye pe, o da wọn lohùn rere, o
bi i pe, Ewo li ekini ninu ofin gbogbo?
29 Jesu si da a lohùn, wipe, Ekini ninu
ofin gbogbo ni, Ẹ gbọ́, Israeli; Oluwa kan
li Oluwa Ọlọrun wa:
30 Ki iwọ ki o si fi gbogbo àiya rẹ, ati
gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo inu rẹ, ati gbo-
gbo agbara rẹ, fẹ Oluwa Ọlọrun rẹ: eyi li
ofin ekini.
31 Ekeji si dabi rẹ̀, eyi, Iwọ fẹ ọmọnike-
ji rẹ bi ara rẹ. Ko si si ofin miran, ti o
tobi jù wọnyi lọ.
32 Akọwe na si wi fun u pe, Olukọni, o
dara, nitõtọ ni iwọ wi: Ọlọrun kanṣoṣo li
o wà; ko si si omiran bikoṣe on:
33 Ati ki a fi gbogbo àiya, ati gbogbo
oyé, ati gbogbo ọkàn, ati gbogbo agbara fẹ
ẹ, ati ki on fẹ ọmọnikeji rẹ̀ bi ara rẹ̀, o jù
gbogbo ọrẹ ẹbọsisun lọ.
34 Nigbati Jesu ri i pe, o fi oyé dahùn,
o wi fun u pe, Iwọ kò jìna si ijọba Ọlọrun.
Lẹhin eyini, kò si ẹnikan ti o jẹ bi i lẽre
kan mọ́.
35 ¶ Nigbati Jesu nkọ́ni ni tempili, o
dahùn wipe, Ẽṣe ti awọn akọwe fi nwipe,
Ọmọ Dafidi ni Kristi iṣe?
36 Nitoriti Dafidi tikararẹ̀ wi nipa Ẹmí
Mimọ́ pe, OLUWA wi fun Oluwa mi pe,
Iwọ joko li ọwọ́ ọtún mi, titi emi o fi sọ
awọn ọtá rẹ di apoti itisẹ rẹ.
37 Njẹ bi Dafidi tikararẹ̀ ba npè e li
Oluwa; nibo li o si ti wa iṣe ọmọ rẹ̀? Ọpọ
awọn enia si fi ayọ̀ gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀.
38 ¶ O si wi fun wọn ninu ẹkọ́ rẹ̀ pe, Ẹ
ma kiyesi awọn akọwe, ti nwọn fẹ lati ma
rìn li aṣọ igunwà gigùn, ti nwọn fẹ ikí-ni li
ọjà.
39 Ati ipò ọlá ninu sinagogu, ati ipò
alàgba li apejẹ àse.
40 Awọn ti o jẹ ile awọn opó run tan, ti
nwọn si ngbadura pipẹ nitori aṣehàn:
awọn wọnyi ni yio jẹbi pọ̀ju.
41 ¶ Jesu si joko leti ibi apoti iṣura, o
si nwò bi awọn enia ti nfi owo wọn sinu
apoti iṣura: ọ̀pọ awọn ti iṣe ọlọrọ̀ si fi pipọ
si i.
42 Talaká opó kan si wá, o fi owo idẹ
wẹ́wẹ meji sinu rẹ̀, ti iṣe idameji owo bàba
kan.
43 O si pè awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ sọdọ rẹ̀, o
si wi fun wọn pe, Lõtọ ni mo wi fun nyin
pe, Talakà opó yi fi sinu apoti iṣura jù gbo-
gbo awọn ti o fi sinu rẹ̀ lọ.
44 Nitori gbogbo wọn fi sinu apoti iṣura
ninu ọ̀pọlọpọ ini wọn; ṣugbọn on ninu
aini rẹ̀ o fi ohun gbogbo ti o ni si i, ani
gbogbo ini rẹ̀.

## ORI 13.

BI o si ti nti tempili jade, ọkan ninu
awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wipe, Olukọni, wò
irú okuta ati irú ile ti o wà nihinyi!
2 Jesu si dahùn wi fun u pe, Iwọ ri ile
nla wọnyi? kì yio si okuta kan ti a o fi
silẹ lori ekeji, ti a kì yio wó lulẹ.
3 Bi o si ti joko lori òke Olifi ti o kọju
si tempili, Peteru ati Jakọbu, ati Johannu
ati Anderu, bi i lẽre nikọ̀kọ wipe,
4 Sọ fun wa, nigbawo ni nkan wọnyi

Digitized by Google

yio ṣẹ? kini yio si ṣe àmi nigbati gbogbo
nkan wọnyi yio ṣẹ?
5 Jesu si da wọn lohùn, o bẹ̀rẹ si iwi pe,
Ẹ ma kiyesi ara, ki ẹnikẹni ki o máṣe tàn
nyin jẹ:
6 Nitori awọn enia pipọ yio wá li orukọ
mi, wipe, Emi ni Kristi; nwọn o si tàn
ọ̀pọlọpọ jẹ.
7 Nigbati ẹnyin ba si ngburó ogun ati
idagìri ogun; ki ẹnyin ki o máṣe kọmnu:
nitori irú nkan wọnyi kò le ṣe ki o ma ṣẹ;
ṣugbọn opin na kì iṣe nisisiyi.
8 Nitoripe orilẹ-ède yio dide si orilẹ-ède,
ati ijọba si ijọba: isẹlẹ yio si wà ni ibi pi-
pọ, ìyan yio si wà ati wahalà: nkan wọnyi
ni ipilẹṣẹ ipọnju.
9 ¶ Ṣugbọn ẹ ma kiyesi ara nyin: nito-
ri nwọn o si fi nyin le ijọ enia lọwọ; a o si
lù nyin ninu sinagogu: a o si mu nyin lọ
sọdọ awọn ijoye ati ọba nitori orukọ mi,
fun ẹrí si wọn.
10 A kò le ṣaima tète wasu Ihin rere na
larin gbogbo orilẹ-ède.
11 Ṣugbọn nigbati nwọn ba nfà nyin, ti
nwọn si nmu nyin lọ, ẹ máṣe gbèro tẹlẹ
bi ẹnyin o ti wi, ki ẹnyin ki o máṣe ronu
ṣiwaju: ṣugbọn ohun ti a ba fifun nyin
ni wakati na, on ni ki ẹnyin ki o wi:
nitori kì iṣe ẹnyin ni nwi, bikoṣe Ẹmí
Mimọ́.
12 Ṣugbọn arakọnrin yio si fi arakọnrin
rẹ̀ hàn fun pipa, ati baba yio fi ọmọ rẹ̀
hàn; awọn ọmọ yio si dide si õbi wọn,
nwọn o si mu ki a pa wọn.
13 A o si korira nyin lọdọ gbogbo enia
nitori orukọ mi: ṣugbọn ẹniti o ba foritì i
titi fi de opin, on na li a o gbalà.
14 ¶ Ṣugbọn nigbati ẹnyin ba si ri irira
ti isọdahoro ni, ti a ti ẹnu woli Danieli sọ,
ti o duro nibiti ko tọ́, (ẹnikẹni ti o ba kà
a, ki o yé e,) nigbana ni ki awọn ti mbẹ ni
Judea sálọ si ori òke:
15 Ki ẹniti mbẹ lori ile ki o má sọkalẹ
lọ sinu ile, ki o má si ṣe wọ̀ inu rẹ̀, lati mu
ohunkohun jade ninu ile rẹ̀:
16 Ki ẹniti mbẹ li oko maṣe pada sẹhin
wá lati mu aṣọ rẹ̀.
17 Ṣugbọn egbé ni fun awọn ti o lóyun,
ati fun awọn ti o nfi ọmu fun ọmọ mu ni
ijọ wọnni!
18 Ki ẹ si ma gbadura, ki sisá nyin ki o
máṣe bọ́ si igba otutù.
19 Nitoriti ipọnju yio wà li ọjọ wọnni,
irú eyi ti kò si lati igba ọjọ ìwa, ti Ọlọrun
da titi fi di akokò yi, irú rẹ̀ ki yio si si.
20 Bi ko si ṣe bi Oluwa ti ke ọjọ wọnni
kuru, kò si ẹda ti iba le là a: ṣugbọn
nitoriti awọn ayanfẹ, o ti ke ọjọ wọnni
kuru.
21 Nitorina bi ẹnikan ba wi fun nyin pe,
Wò o, Kristi mbẹ nihinyi; tabi, wò o, o
mbẹ lọhun; ẹ máṣe gbà a gbọ́:
22 Nitori awọn eke Kristi, ati eke woli
ni yio dide, nwọn o si fi àmi ati ohun
iyanu hàn, tobẹ̃ bi o le ṣe, ti nwọn iba
fi tàn awọn ayanfẹ pãpã.
23 Ṣugbọn ẹ kiyesi i: wò o, mo sọ ohun
gbogbo fun nyin tẹlẹ.
24 ¶ Ṣugbọn li ọjọ wọnni, lẹhin ipọnju
na, õrùn yio ṣõkun, oṣupá kì yio si fi
imọlẹ rẹ̀ hàn,
25 Awọn irawọ oju ọrun yio já silẹ̀, ati
agbara ti mbẹ li ọrun li a o si mìtiti.
26 Nigbana ni nwọn o si ri Ọmọ-enia ti
yio ma ti oju ọrun bọ̀ ti on ti agbara ati
ogo nla.
27 Nigbana ni yio si rán awọn angeli rẹ̀,
yio si kó gbogbo awọn ayanfẹ rẹ̀ lati ori
igun mẹrẹrin aiye jọ, lati ikangun aiye titi
de ikangun ọrun.
28 Nisisiyi ẹ kọ́ owe igi ọpọtọ; Nigbati
ẹká rẹ̀ ba yọ titun, ti o ba si ru ewé, ẹnyin
mọ̀ pe igba ẹ̃rùn sunmọ etile:
29 Gẹgẹ bẹ̃ na li ẹnyin, nigbati ẹnyin ba
ri nkan wọnyi ti nṣẹ, ki ẹ mọ̀ pe o sunmọ
etile tan lẹhin ilẹkun.
30 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Iran yi kì
yio rekọja, titi a o fi mu gbogbo nkan
wọnyi ṣẹ.
31 Ọrun on aiye yio rekọja: ṣugbọn ọ̀rọ
mi kì yio rekọja.
32 ¶ Ṣugbọn niti ọjọ ati wakati na, kò
si ẹnikan ti o mọ̀ ọ, kò si, ki iṣe awọn
angeli ọrun, tabi Ọmọ, bikoṣe Baba mi ni-
kanṣoṣo.
33 Ki ẹnyin ki o ma kiyesi, ki ẹ si ma
ṣọra, ki ẹ si ma gbadura: nitori ẹnyin ko
mọ̀ igba ti akokò na yio de.
34 ¶ Nitori Ọmọ-enia dabi ọkọnrin kan
ti nlọ àjo ti o jìna rére, ẹniti o fi ile rẹ̀ silẹ,
ti o si fi aṣẹ fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀, ati iṣẹ
olukuluku fun u, ti o si fi aṣẹ fun oluṣọna
ki o ma ṣọna.
35 Njẹ ki ẹnyin ki o ma ṣọna: nitori
ẹnyin ko mọ̀ igba ti bãle ile mbọ̀ wá, bi li
alẹ ni, tabi larin ọganjọ, tabi li akukọ, tabi
li owurọ̀:
36 Pe, nigbati o ba de li ojijì, ki o máṣe
ba nyin li oju orun.
37 Ohun ti mo wi fun nyin, mo wi fun
gbogbo enia, Ẹ ma ṣọra.

Digitized by Google

## ORI 14.

LẸHIN ọjọ meji ni ajọ irekọja, ati ti
aiwukara: ati awọn olori alufa ati
awọn akọwe nwá ọ̀na bi nwọn iba ti fi ẹ̀tan
mu u, ki nwọn ki o pa a.
2 Ṣugbọn nwọn wipe, Ki iṣe li ọjọ ajọ,
ki ariwo ki o má ba wà ninu awọn enia.
3 ¶ Nigbati o si wà ni Betani ni ile
Simoni adẹtẹ̀, bi o ti joko tì onjẹ, obirin
kan ti o ni ẹ̀ba (oruba) alabasta turari tutù
iyebiye, o wá, o si fọ́ ẹ̀ba na, o si ndà a si i
lori.
4 Awọn kan si wà ti inu wọn ru ninu
ara wọn, nwọn si wipe, Nitori kili a ṣe nfi
turari yi ṣòfo?
5 A ba sá tà turari tutù yi jù ìwọn ọ̃du-
run owo idẹ́ lọ, a ba si fifun awọn talakà.
Nwọn si nkùn si i.
6 Ṣugbọn Jesu wipe, Ẹ jọwọ rẹ̀ si; ẽṣe
ti ẹnyin fi mba a wi? iṣẹ rere li o ṣe si mi
lara.
7 Nigbagbogbo li ẹnyin sá ni talakà pẹlu
nyin, ki ẹnyin ki o si ma ṣore fun wọn ni-
gbakugba ti ẹnyin fẹ; ṣugbọn ẹnyin ko ni
mi nigbagbogbo.
8 O ṣe ìwọn eyi ti o le ṣe: o wá ṣiwaju
lati fi oróro kùn ara mi fun sisinku ni.
9 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Nibikibi ti a
o gbé wasu ihin-rere yi ni gbogbo aiye,
nibẹ̀ pẹlu li a o si rò ihin eyi ti obirin yi ṣe
lati fi ṣe iranti rẹ̀.
10 ¶ Judasi Iskariotu ọkan ninu awọn
mejila, si tọ̀ awọn olori alufa lọ, lati fi i
hàn fun wọn.
11 Nigbati nwọn si gbọ́, nwọn yọ̀ gidi-
gidi, nwọn si ṣe ileri lati fun u li owo. O
si nwá ọ̀na lati fi i hàn.
12 ¶ Li ọjọ kini ajọ aiwukara, nigbati
nwọn npa ẹran irekọja, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
si wi fun u pe, Nibo ni iwọ nfẹ ki a pèse
silẹ dè ọ, ki iwọ́ ki o le jẹ irekọja.
13 O si rán awọn meji ninu awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀, o si wi fun wọn pe, Ẹ lọ si ilu,
ọkọnrin kan ti nrù ìṣa omi yio pade nyin:
ẹ mã tọ̀ ọ lẹhin.
14 Ati ibikibi ti o ba gbè wọ̀, ki ẹnyin
ki o wi fun bãle na pe, Olukọni wipe, Nibo
ni gbàngan apejẹ na gbé wà, nibiti emi o
gbé jẹ irekọja pẹlu awọn ọmọ-ẹhin mi?
15 On o si fi gbàngan nla kan loke hàn
nyin, ti a ṣe lọṣọ, ti a si pèse tẹlẹ; nibẹ̀ ni
ki ẹnyin ki o pèse silẹ dè wa.
16 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si jade lọ, nwọn
wá si ilu, nwọn si ri i gẹgẹ bi o ti sọ fun
wọn: nwọn si pèse irekọja silẹ.
17 Nigbati alẹ lẹ, o wá pẹlu awọn me-
jila.
18 Bi nwọn si ti joko ti nwọn njẹun,
Jesu wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, Ọkan
ninu nyin ti mba mi jẹun yio fi mi hàn.
19 Nwọn si bẹ̀rẹ si ikãnu gidigidi, ati si
ibi i lẽre lọkọ̃kan wipe, Emi ni bi? ekeji si
wipe, Emi ni bi?
20 O si dahùn o si wi fun wọn pe, Ọkan
ninu awọn mejila, ti o ntọwọ bọ̀ inu awo
pẹlu mi ni.
21 Nitõtọ Ọmọ-enia nlọ bi a ti kọwe
nipa tirẹ̀: ṣugbọn egbé ni fun ọkọnrin na,
lọdọ ẹniti a gbé ti fi Ọmọ-enia hàn! iba
san fun ọkọnrin na, bi o ṣepe a kò bí i.
22 ¶ Bi nwọn si ti njẹun, Jesu mu aka-
ra, o si sure, o si bu u, o si fifun wọn, o
wipe, Gbà, jẹ: eyiyi li ara mi.
23 O si mu ago, nigbati o si sure tan,
o fifun wọn: gbogbo nwọn si mu ninu
rẹ̀.
24 O si wi fun wọn pe, Eyi li ẹ̀jẹ mi ti
majẹmu titun, ti a tà silẹ fun ọ̀pọ enia.
25 Lõtọ ni mo wi fun nyin, emi kì yio
mu ninu eso ajara mọ, titi yio fi di ọjọ
na, nigbati emi o mu u ni titun ni ijọba
Ọlọrun.
26 ¶ Nigbati nwọn si kọ orin kan tan,
nwọn jade lọ sori òke Olifi.
27 Jesu si wi fun wọn pe, Gbogbo nyin
ni yio kọsẹ̀ lara mi li oru oni: nitoriti a ti
kọwe rẹ̀ pe, Emi o lù oluṣọ agutan, a o si
tú agbo agutan ká kiri.
28 Ṣugbọn lẹhin igba ti mo ba jinde,
emi o ṣaju nyin lọ si Galili.
29 Ṣugbọn Peteru wi fun u pe, Bi gbo-
gbo enia tilẹ kọsẹ̀, ṣugbọn emi kọ́.
30 Jesu si wi fun u pe, Lõtọ̀ ni mo wi
fun ọ pe, loni yi, ani li alẹ yi, ki akukọ
ki o to kọ nigba meji, iwọ o sẹ́ mi nigba
mẹta.
31 Ṣugbọn o tẹnumọ ọ gidigidi wipe, Bi
o tilẹ di ati ba ọ kú, emi ko jẹ sẹ́ ọ bi o
ti wù ki o ri. Gẹgẹ bẹ̃ni gbogbo wọn wi
pẹlu.
32 Nwọn si wá si ibi kan ti a npè ni
Getsemane: o si wi fun awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀ pe, Ẹ joko nihinyi, nigbati mo ba lọ
igbadura.
33 O si mu Peteru ati Jakọbu ati
Johannu pẹlu rẹ̀, ẹnu si bẹrẹ si yà a gidi-
gidi, o si rẹ̀ ẹ pupọ.
34 O si wi fun wọn pe, Ọkàn mi nkãnu
gidigidi titi de ikú: ẹ duro nihin, ki ẹ si
ma ṣọna.
35 O si lọ siwaju diẹ, o si dojubolẹ, o si

Digitized by Google

gbadura pe, bi o ba le ṣe, ki wakati na le
kọja kuro lori rẹ̀.
36 O si wipe, Abba, Baba, ṣiṣe li ohun
gbogbo fun ọ; mù ago yi kuro lori mi:
ṣugbọn kì iṣe eyiti emi fẹ, bikoṣe eyiti iwọ
fẹ.
37 O si wá, o ba wọn, nwọn nsùn, o si
wi fun Peteru pe, Simoni, iwọ nsùn? iwọ
kò le ṣọna ni wakati kan?
38 Ẹ ma ṣọna, ki ẹ si ma gbadura, ki ẹ
má ba bọ́ sinu idẹwò. Lõtọ li ẹmí nfẹ,
ṣugbọn o ṣe ailera fun ara.
39 O si tún pada lọ, o si gbadura, o nsọ
ọ̀rọ kanna.
40 Nigbati o si pada wá, o tún bá wọn,
nwọn nsùn, nitoriti oju wọn kún fun
orun, bẽni nwọn kò si mọ̀ èsi ti nwọn iba
fifun u.
41 O si wá li arinkẹta, o si wi fun wọn
pe, Ẹ mã sùn wayi, ki ẹ si mã simi: o to
bẽ, wakati na de; wo o, a fi Ọmọ-enia le
awọn ẹlẹṣẹ lọwọ.
42 Ẹ dide, ki a ma lọ; wò o, ẹniti o fi
mi hàn sunmọ tosi.
43 ¶ Lojukanna, bi o si ti nsọ lọwọ,
Judasi de, ọkan ninu awọn mejila, ati ọ̀pọ
enia pẹlu rẹ̀ ti awọn ti idà, pẹlu ọgọ, lati
ọdọ olori alufa, ati awọn akọwe, ati awọn
alàgba wá.
44 Ẹniti o si fi i hàn ti fi àmi fun wọn,
wipe, Ẹnikẹni ti mo ba fi ẹnu kò li ẹnu,
on na ni; ẹ mu u, ki ẹ si ma fà a lọ li
alafia.
45 Nigbati o de, o tọ̀ ọ lọ gan, o wipe,
Olukọni, olukọni! o si fi ẹnu kò o li ẹnu.
46 ¶ Nwọn si gbé ọwọ́ wọn le e, nwọn
si mu u.
47 Ṣugbọn ọkan ninu awọn ti o duro
nibẹ̀ fà idà yọ, o si ṣá ọmọ-ọdọ olori alufa,
o si ke etí rẹ̀ kuro.
48 Jesu si dahùn o si wi fun wọn pe,
Emi li ẹnyin jade tọ̀ wá bi olè, ti ẹnyin ti
idà ati ọgọ lati mu?
49 Li ojojumọ li emi wà pẹlu nyin ni
tempili, ti emi nkọ́ nyin, ẹnyin kò si mu
mi: ṣugbọn Iwe mimọ kò le ṣe alaiṣẹ.
50 Gbogbo wọn si fi i silẹ, nwọn si sà
lọ.
51 Ọmọkọnrin kan si ntọ̀ ọ lẹhin, ti o fi
aṣọ ọgbọ bò ìhoho rẹ̀; awọn ọmọ-ogun si
gbá a mu:
52 O si jọwọ aṣọ ọgbọ na lọwọ, o si sá
kuro lọdọ wọn nihoho.
53 ¶ Nwọn si mu Jesu lọ sọdọ olori
alufa: gbogbo awọn olori alufa, ati awọn
alàgba, ati awọn akọwe si pejọ pẹlu rẹ̀.
54 Peteru si tọ̀ ọ lẹhin li òkere titi fi de
agbala olori alufa; o si bá awọn ọmọ-ọdọ
joko, o si nyána.
55 Awọn olori alufa ati gbogbo ajọ ìgbi-
mọ nwá ẹlẹri si Jesu lati pa a; nwọn kò si
ri ohun kan.
56 Nitoripe ọ̀pọlọpọ li o jẹri eke si i,
ṣugbọn ohùn awọn ẹlẹri na kò ṣọkan.
57 Awọn kan si dide, nwọn njẹri eke si
i, wipe,
58 Awa gbọ́ o wipe, Emi o wó tempili
yi ti a fi ọwọ́ ṣe, niwọn ijọ mẹta emi o si
kọ́ omiran ti a kò fi ọwọ́ ṣe.
59 Ati ninu eyi na pẹlu, ohùn wọn kò
ṣọkan.
60 Olori alufa si dide duro larin, o si bi
Jesu lẽre, wipe, Iwọ kò dahùn kan? kili
eyi ti awọn wọnyi njẹri si ọ?
61 Ṣugbọn Jesu dakẹ, ko si dahùn ohun
kan. Olori alufa si tun bi i lẽre, o wi
fun u pe, Iwọ ni Kristi na, Ọmọ Olubukun
nì?
62 Jesu si wipe, Emi ni: ẹnyin o si ri
Ọmọ-enia joko li ọwọ́ ọtún agbara, yio si
ma ti inu awọsanma ọrun wá.
63 Nigbana li olori alufa fà aṣọ rẹ̀ ya, o
wipe, Ẹlẹri kili a si nwá?
64 Ẹnyin gbọ́ ọ̀rọ òdi si Ọlọrun na:
ẹnyin ti rò o si? Gbogbo wọn si da a lẹbi
pe, o jẹbi ikù.
65 Awọn miran si bẹ̀rẹ si itutọ́ si i lara,
ati si ibò o loju, ati si ikàn a lẹṣẹ́, nwọn si
wi fun u pe, Sọtẹlẹ: awọn onṣẹ si nfi atẹlẹ
ọwọ́ wọn gbá a loju.
66 ¶ Bi Peteru si ti wà ni isalẹ li ãfin,
ọkan ninu awọn ọmọbirin olori alufa wá:
67 Nigbati o si ri ti Peteru nyána, o wò
o, o si wipe, Iwọ pelu ti wà pẹlu Jesu ti
Nasareti.
68 Ṣugbọn o sẹ́, wipe, Emi ko mọ̀, oyé
ohun ti iwọ nwi kò tilẹ yé mi. O si jade
lọ si iloro; akukọ si kọ.
69 Ọmọbirin kan si tún ri i, o si bẹ̀rẹ si
iwi fun awọn ti o duro nibẹ̀ pe, Ọkan ninu
wọn ni eyi.
70 O si tún sẹ́. O si pẹ diẹ, awọn ti o
duro nibẹ̀ tún wi fun Peteru pe, Lõtọ ni
ọkan ninu wọn ni iwọ iṣe: nitoripe ara
Galili ni iwọ, ohùn rẹ si jọ bẹ̀.
71 Ṣugbọn o bẹ̀rẹ si iré ati si ibura,
wipe, Emi ko mọ̀ ọkọnrin yi ẹniti ẹnyin
nwi.
72 Akukọ si kọ larinkeji. Peteru si
ranti ọ̀rọ ti Jesu wi fun u pe, Ki akukọ ki
o to kọ larinmeji, iwọ o sẹ́ mi larinmẹta.
Nigbati o si rò o, o sọkun.

Digitized by Google

## ORI 15.

LOJUKANNA li owurọ̀, awọn olori alufa
jọ gbìmọ pẹlu awọn alàgba, ati awọn
akọwe, ati gbogbo ajọ igbimọ, nwọn si dè
Jesu, nwọn si mu u lọ, nwọn si fi i le
Pilatu lọwọ.
2 Pilatu si bi i lẽre, wipe, Iwọ ha li Ọba
awọn Ju? O si dahùn wi fun u pe, Iwọ
wi i.
3 Awọn olori alufa si fi i sùn li ohun
pipọ: ṣugbọn on ko dahùn kan.
4 Pilatu si tún bi i lẽre, wipe, Iwọ ko
dahùn ohun kan? wò ọ̀pọ ohun ti nwọn
njẹri si ọ.
5 Ṣugbọn Jesu ko da a ni gbolohùn
kan; tobẽ ti ẹnu yà Pilatu.
6 Nigba ajọ na, on ama dá ondè kan
silẹ fun wọn, ẹnikẹni ti nwọn ba fẹ.
7 Ẹnikan si wà ti a npè ni Barabba,
ẹniti a sọ sinu tubu pẹlu awọn ti o ṣọ̀tẹ
pẹlu rẹ̀, awọn ẹniti o si pania pẹlu ninu
iṣọtẹ na.
8 Ijọ enia si bẹ̀rẹ si ikigbe soke li ohùn
rara, nwọn nfẹ ki o ṣe bi on ti ima ṣe fun
wọn ri,
9 Ṣugbọn Pilatu da wọn lohùn, wipe,
Ẹnyin nfẹ ki emi ki o da Ọba awọn Ju silẹ
fun nyin?
10 On sá ti mọ̀ pe nitori ilara ni awọn
ọlori alufa ṣe fi i le on lọwọ.
11 Ṣugbọn awọn olori alufa rú awọn
enia soke pe, ki o kuku dá Barabba silẹ
fun wọn.
12 Pilatu si dahùn o tún wi fun wọn
pe, Kili ẹnyin ha nfẹ ki emi ki o ṣe si ẹniti
ẹnyin npè li Ọba awọn Ju?
13 Nwọn si tún kigbe soke, wipe, Kàn
a mọ agbelebu.
14 Nigbana ni Pilatu si bi wọn lẽre,
wipe, Eṣe? buburu kili o ṣe? Nwọn
si kigbe soke gidigidi, wipe, Kàn a mọ
agbelebu.
15 ¶ Pilatu si nfẹ ṣe eyi ti o wù awọn
enia, o da Barabba silẹ fun wọn. Nigbati
o si nà Jesu tan, o fà a le wọn lọwọ lati
kàn a mọ agbelebu.
16 Awọn ọmọ-ogun si fà a jade lọ sinu
gbàngan, ti a npè ni Pretorioni; nwọn si
pè gbogbo ẹgbẹ awọn ọmọ-ogun jọ.
17 Nwọn si fi aṣọ elesè àluko wọ̀ ọ,
nwọn wun ade ẹgún, nwọn si fi dé e li
ori,
18 Nwọn si bẹ̀rẹ si ikí i, wipe, Alafia,
Ọba awọn Ju!
19 Nwọn si fi ọpá iyè lù u lori, nwọn si
tutọ́ si i lara, nwọn si kunlẹ niwaju rẹ̀,
nwọn si foribalẹ fun u.
20 Nigbati nwọn si sin i jẹ tan, nwọn
si bọ́ aṣọ elesè àluko na kuro lara rẹ̀, nwọn
si fi aṣọ rẹ̀ wọ̀ ọ, nwọn si mu u jade lọ lati
kàn a mọ agbelebu.
21 Nwọn si fi agbara mu ọkọnrin kan,
Simoni ara Kirene, ẹniti nkọja lọ ti nti
igberiko bọ̀, baba Aleksanderu ati Rufu,
lati rù agbelebu rẹ̀.
22 Nwọn si mu u wá si ibi ti a npè ni
Golgota, itumọ rẹ̀ ni, Ibi agbari.
23 Nwọn si fi ọti-waini ti a dàpọ mọ
ojia fun u lati mu: ṣugbọn on kò gbà a.
24 Nigbati nwọn si kàn a mọ agbelebu
tan, nwọn si pín aṣọ rẹ̀, nwọn si ṣẹ gège
lori wọn, eyi ti olukuluku iba mu.
25 Ni wakati kẹta ọjọ, on ni nwọn kàn
a mọ agbelebu.
26 A si kọwe akọle ọ̀ran ifisùn rẹ̀ si
igberi rẹ̀, ỌBA AWỌN JU.
27 Nwọn si kàn awọn olè meji mọ agbe-
lebu pẹlu rẹ̀; ọkan li ọwọ́ ọtún, ati ekeji li
ọwọ́ òsi rẹ̀.
28 Iwe mimọ si ṣẹ, ti o wipe, A si kà a
pẹlu awọn arufin.
29 Awọn ti nrekọja lọ si nfi i ṣe ẹlẹyà,
nwọn si nmì ori wọn, wipe, A, Iwọ ti o wó
tempili, ti o si kọ́ ọ ni ijọ mẹta,
30 Gbà ara rẹ, ki o si sọkalẹ lati ori
agbelebu wá.
31 Gẹgẹ bẽli awọn olori alufa pẹlu, nwọn
nsin i jẹ ninu ara wọn pẹlu awọn akọwe,
wipe, O gbà awọn ẹlọmiran là; kò le gbà
ara rẹ̀.
32 Jẹ ki Kristi, Ọba Israeli, sọkalẹ lati
ori agbelebu wá nisisiyi, ki awa ki o le ri i,
ki a si le gbagbọ́. Awọn ti a kàn mọ
agbelebu pẹlu rẹ̀ si nfi i ṣe ẹlẹyà.
33 Nigbati o di wakati kẹfa, òkunkun
si ṣú bò gbogbo ilẹ titi o fi di wakati kẹsan.
34 Ni wakati kẹsan ni Jesu si kigbe
soke li ohùn rara, wipe, Eloi, Eloi, lama
sabaktani? itumọ eyi ti iṣe, Ọlọrun mi,
Ọlọrun mi, ẽṣe ti iwọ fi kọ̀ mi silẹ?
35 Nigbati awọn kan ninu awọn ti o
duro nibẹ̀ gbọ́ eyi, nwọn wipe, Wò o, o npè
Elijah.
36 Ẹnikan si sare, o fi spunge bọ ọti
kikan, o fi le ori ọpá iyè, o fifun u mu,
wipe, Ẹ jọwọ rẹ̀ si; ẹ jẹ ki a ma wò bi
Elijah yio wá gbé e sọkalẹ.
37 Jesu si kigbe soke li ohùn rara, o jọwọ
ẹmi rẹ̀ lọwọ.
38 Aṣọ ikele ti tempili si fà ya ni meji
lati oke de isalẹ.

Digitized by Google

39 ¶ Nigbati balogun ọrún, ti o duro niha ọdọ rẹ̀, ri ti o kigbe soke bayi, ti o si jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ, o wipe, Lõtọ Ọmọ Ọlọrun li ọkọnrin yi iṣe.

40 Awọn obirin pẹlu si wà li òkere nwọn nwò: ninu awọn ẹniti Maria Magdalene wà, ati Maria iya Jakọbu kekere, ati ti Jose ati Salome;

41 (Awọn ẹniti, nigbati o wà ni Galili, ti nwọn ntọ̀ ọ lẹhin pẹlu, nwọn nṣe iranṣẹ fun u;) ati ọ̀pọ obirin miran pẹlu, ti o ba a goke wá si Jerusalemu.

42 ¶ Nigbati alẹ si lẹ, nitoriti iṣe ọjọ ipalẹmọ, eyini ni, ọjọ ti o ṣiwaju ọjọ isimi,

43 Josefu ara Arimatea, ọlọlá ìgbimọ, ẹniti o si nreti ijọba Ọlọrun pẹlu, o wá, o si wọle tọ̀ Pilatu lọ laifòya, o si tọrọ okú Jesu.

44 Ẹnu si yà Pilatu gidigidi, bi o ti kú na: o si pè balogun ọrún, o bi i lẽre bi igba ti o ti kú ti pẹ diẹ.

45 Nigbati o si mọ̀ lati ọdọ balọgun ọrún na, o si fi okú na fun Josefu.

46 O si rà aṣọ ọgbọ àla wá, o si sọ̀ ọ kalẹ, o si fi aṣọ ọgbọ àla na dì i, o si tẹ́ ẹ sinu ibojì ti a wọ̀ ninu apata, o si yi okuta kan dí ẹnu-ọ̀na ibojì na.

47 Ati Maria Magdalene, ati Maria iya Jose, ri ibi ti a gbé tẹ́ ẹ si.

## ORI 16.

NIGBATI ọjọ isimi si kọja tan, Maria Magdalene, ati Maria iya Jakọbu, ati Salome, ti rà turari ki nwọn ba wá lati fi kùn u.

2 Ni kutukutu owurọ̀ ọjọ kini ọ̀sẹ, nwọn wá si ibi ibojì nigbati õrùn bẹ̀rẹ si ilà.

3 Nwọn si mba ara wọn ṣe aroye, wipe, Tani yio yi okuta kuro fun wa li ẹnu ibojì?

4 Nigbati nwọn si wò o, nwọn ri pe a ti yi okuta na kuro: nitoripe o tobi gidigidi.

5 Nigbati nwọn si wọ̀ inu ibojì, nwọn ri ọmọkọnrin kan joko li apa ọtún, ti o wọ̀ agbada funfun gigun; ẹ̀ru si ba wọn.

6 O si wi fun wọn pẹ, Ẹ má bẹ̀ru: ẹnyin nwá Jesu ti Nasareti, ti a kàn mọ agbelebu: o jinde; kò si nihinyi: ẹ wò ibi ti nwọn gbé tẹ́ ẹ si.

7 Ṣugbọn ẹ ba ọ̀na nyin lọ, ẹ si wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ ati Peteru pe, o ṣaju nyin lọ si Galili: nibẹ̀ li ẹnyin o gbe ri i, bi o ti wi fun nyin.

8 Nwọn si jade lọ kánkan, nwọn si sá kuro ni ibojì; nitoriti nwọn nwarìri, ẹ̀ru si ba wọn gidigidi: bẽni nwọn ko wi ohunkohun fun ẹnikan; nitoripe ẹ̀ru ba wọn.

9 ¶ Nigbati Jesu jinde li owurọ̀ kutukutu ni ijọ kini ọ̀sẹ, o tète fi ara hàn fun Maria Magdalene, lara ẹniti o lé ẹmi èṣu meje jade.

10 On si lọ sọ fun awọn ti o ti mba a gbé, bi nwọn ti ngbàwẹ, ti nwọn si nsọkun.

11 Ati awọn, nigbati nwọn si gbọ́ pe o di alãye, ati pe, a si ti ri i lọdọ rẹ̀, nwọn kò gbagbọ́.

12 ¶ Lẹhin eyini, o si fi ara hàn fun awọn meji ninu wọn ni ipa miran, bi nwọn ti nrìn li ọ̀na, ti nwọn si nlọ si igberiko.

13 Nwọn si lọ sọ fun awọn iyokù: nwọn kò si gbà wọn gbọ́ pẹlu.

14 ¶ Lẹhin na o si fi ara hàn fun awọn mọkanla bi nwọn ti joko tì onjẹ, o si fi aigbagbọ́ ati lile àiya wọn ba wọn wi, nitoriti nwọn ko gbà awọn ti o ti ri i lẹhin igbati o jinde gbọ́.

15 O si wi fun wọn pe, Ẹ lọ si gbogbo aiye, ki ẹ si ma wasu Ihin rere fun gbogbo ẹda.

16 Ẹniti o ba gbagbọ́, ti a ba si baptisi rẹ̀ yio là; ṣugbọn ẹniti kò ba gbagbọ́ yio jẹbi.

17 Àmi wọnyi ni yio si ma ba awọn ti o gbagbọ́ lọ; Li orukọ mi ni nwọn o ma lé awọn ẹmi èṣu jade; nwọn o si ma fi ède titun sọ̀rọ;

18 Nwọn o si ma gbé ejò lọwọ; bi nwọn ba si mu ohunkohun ti o li oró, kì yio pa wọn lara; nwọn o gbé ọwọ́ le awọn olokunrun, ara wọn o da.

19 ¶ Bẽni nigbati Oluwa si ti ba wọn sọ̀rọ tan, a si gbà a lọ soke ọrun, o si joko li ọwọ́ ọtún Ọlọrun.

20 Nwọn si jade lọ, nwọn si nwasu ni ibi gbogbo, Oluwa si mba wọn ṣiṣẹ, o si nfi idi ọ̀rọ na kalẹ pẹlu nipa àmi ti ntẹ̀le e. Amin.

Digitized by Google

IHIN RERE

TI

# LUKU.

## ORI 1.

NIWỌNBI ọ̀pọ enia ti dawọle e lati tò
ìhin wọnni jọ lẹsẹsẹ, eyiti o ti mulẹ
ṣinṣin lãrin wa,
2 Ani gẹgẹ bi awọn ti o ṣe oju wọn lati
ibẹrẹ, ti nwọn si jasi iranṣẹ ọrọ na, ti nawọ
wọn si wa;
3 O si yẹ fun mi pẹlu, ti mo ti tọsẹ̀
ohun gbogbo kinikini lati ipilẹṣẹ, lati
kọwe si ọ li oriori, Teofilu ọlọlajùlọ,
4 Ki iwọ ki o le mọ̀ otitọ ohun wọnni,
ti a ti kọ́ ọ.
5 ¶ Nigba ọjọ Herodu ọba Judea, alufa
kan wà, ni ipa ti Abia, orukọ rẹ̀ a ma jẹ
Sakariah: aya rẹ̀ si ṣe ọkan ninu awọn
ọmọbirin Aaroni, orukọ rẹ̀ a si ma jẹ
Elisabeti.
6 Awọn mejeji si ṣe olododo niwaju
Ọlọrun, nwọn nrin ni gbogbo ofin on ìlana
Oluwa li ailẹgan.
7 Ṣugbọn nwọn kò li ọmọ, nitori ti
Elisabeti yàgan, awọn mejeji si di arugbo.
8 O si ṣe, nigbati o nṣe iṣẹ alufa niwaju
Ọlọrun ni ipa ẹsẹ tirẹ̀,
9 Bi iṣe awọn alufa, ipa tirẹ̀ ni ati ma fi
turari jóna, nigbati o ba wọ̀ inu tempili
Oluwa lọ.
10 Gbogbo ijọ awọn enia si ngbadura
lode li akokò sisun turari.
11 Angeli Oluwa kan si fi ara hàn a, o
duro li apa ọtún pẹpẹ turari.
12 Nigbati Sakariah si ri i, ori rẹ̀ wúle,
ẹ̀ru si ba a.
13 Ṣugbọn angeli na wi fun u pe, Má
bẹ̀ru, Sakariah: nitoriti adura rẹ gbà;
Elisabeti aya rẹ yio si bí ọmọkọnrin kan
fun ọ, iwọ o si sọ orukọ rẹ̀ ni Johannu.
14 Iwọ o si li ayọ̀ ati inu didùn: enia
pipọ yio si yọ̀ si ibí rẹ̀.
15 Nitori on o pọ̀ niwaju Oluwa, kì yio
si mu ọti-waini, bẹ̃ni kì yio si mu ọti-kọti;
yio si kún fun Ẹmí Mimọ́ ani lati inu iya
rẹ̀ wá.
16 On o si pa pipọ dà ninu awọn ọmọ
Israeli si Oluwa Ọlọrun wọn.
17 Ẹmí ati agbara Elijah ni on o si fi
ṣaju rẹ̀ lọ, lati pa àiya awọn baba dà si ti
awọn ọmọ, ati ti awọn alaigbọran si ọgbọ́n
awọn olõtọ; ki o le pèse enia ti a mura silẹ
dè Oluwa.
18 Sakariah si wi fun angeli na pe, Àmi
wo li emi o fi mọ̀ eyi? Emi sá di arugbo,
ati Elisabeti aya mi si sunmọ iwaju li ọjọ
rẹ̀.
19 Angeli na si dahùn o wi fun u pe,
Emi ni Gabrieli, ti ima duro niwaju Ọlọrun;
emi li a rán wá lati sọ fun ọ, ati lati mu
ìhin ayọ̀ wọnyi fun ọ wa.
20 Si kiyesi i, iwọ o yadi, iwọ kì yio si
le fọhun, titi ọjọ na ti nkan wọnyi yio fi
ṣẹ, nitori iwọ kò gbà ọ̀rọ mi gbọ́ ti yio ṣẹ li
akokò wọn.
21 Awọn enia si duro dè Sakariah, ẹnu
si yà wọn nitoriti o pẹ ninu tempili.
22 Nigbati o si jade, kò le fọhun si wọn:
nwọn si woye pe o ri iran ninu tempili:
nitoriti o nṣe apẹrẹ si wọn, o si yà odi.
23 O si ṣe, nigbati ọjọ iṣẹ alufa rẹ̀ pé, o
lọ si ile rẹ̀.
24 Lẹhin ọjọ wọnni ni Elisabeti aya rẹ̀
lóyun, o si fi ara rẹ̀ pamọ́ li oṣù marun, o
ni,
25 Bayi li Oluwa ṣe fun mi li ọjọ ti o
ṣijuwò mi, lati mu ẹ̀gan mi kuro lọdọ
araiye.
26 Li oṣù kẹfa a si rán angeli Gabrieli
lati ọdọ Ọlọrun lọ si ilu kan ni Galili, ti a
npè ni Nasareti,
27 Si Wundia kan ti a fẹ fun ọkọnrin
kan, ti a npè ni Josefu, ti idile Dafidi;
orukọ wundia na a si ma jẹ Maria.
28 Angeli na si tọ̀ ọ wá, o ni, Alafia,
iwọ ẹniti a kọjusi ṣe li ore, Oluwa pẹlu rẹ:
alabukun-fun ni iwọ ninu awọn obirin.
29 Ṣugbọn ọkàn rẹ̀ kò lelẹ nitori ọ̀rọ rẹ̀,
o si rò ninu ara rẹ̀ pe, irú kíki kili eyi.
30 Angeli na si wi fun u pe, Má bẹ̀ru,



Digitized by Google

Maria: nitori iwọ ti ri oju rere lọdọ Ọlọ-
run.
31 Sá si kiyesi i, iwọ o lóyun ninu rẹ,
iwọ o si bí ọmọkọnrin kan, iwọ o si pè orukọ
rẹ̀ ni JESU.
32 On o pọ̀, Ọmọ Ọgá-ogo li a o si ma
pè e: Oluwa Ọlọrun yio si fi itẹ́ Dafidi baba
rẹ̀ fun u:
33 Yio si jọba ni ile Jakọbu titi aiye;
ijọba rẹ̀ kì yio si ni ipẹkun.
34 Nigbana ni Maria wi fun angeli na
pe, Bawo li eyi o ti ri, nigbati emi kò ti
mọ̀ ọkọnrin?
35 Angeli na si dahùn o si wi fun u pe,
Ẹmí Mimọ́ yio tọ̀ ọ wá, ati agbara Ọgá-ogo
yio ṣiji bò ọ: nitorina ohun Mimọ́ ti a o ti
inu rẹ bi, Ọmọ Ọlọrun li a o ma pè e.
36 Si kiyesi i, Elisabeti ará rẹ, on pẹlu
si lóyun ọmọkọnrin kan li ogbologbo rẹ̀:
eyi si li oṣu kẹfa fun ẹniti a npè li agàn.
37 Nitori kò si ohun ti o ṣoro fun Ọlọrun.
38 Maria si wipe, Wò ọmọ-ọdọ Oluwa;
ki o ri fun mi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ. Angeli na si
fi i silẹ lọ.
39 Ni ijọ wọnni ni Maria si dide, o lọ
kánkan si ilẹ-òke, si ilu kan ni Juda;
40 O si wọ̀ ile Sakariah lọ, o si kí Elisa-
beti.
41 O si ṣe, nigbati Elisabeti gbọ́ kikí
Maria, ọlẹ̀ sọ ninu rẹ̀; Elisabeti si kún fun
Ẹmí Mimọ́:
42 O si ke li ohùn rara, o si wipe, Ala-
bukun-fun ni iwọ ninu awọn obirin, alabu-
kun-fun si ni fun ọmọ̀ inu rẹ.
43 Nibo si li eyi ti wá ba mi, ti iya
Oluwa mi iba fi tọ̀ mi wá?
44 Sawò o, bi ohùn kikí rẹ ti bọ́ si mi li
etí, ọlẹ̀ sọ ninu mi fun ayọ̀.
45 Alabukun-fun si li ẹniti o gbagbọ́:
nitori ṣiṣẹ ti nkan wọnyi yio ṣẹ, ti a ti sọ
fun u lati ọdọ Oluwa wá.
46 Maria si dahùn, o ni, Ọkàn mi yìn
Oluwa logo,
47 Ẹmí mi si yọ̀ si Ọlọrun Olugbala
mi.
48 Nitoriti o ṣiju-wò ìwa irẹlẹ ọmọbirin
ọdọ rẹ̀: sá wò o, lati isisiyi lọ gbogbo iran
enia ni yio ma pè mi li alabukun-fun.
49 Nitori ẹniti o li agbara ti ṣe ohun ti
o tobi fun mi; mimọ́ si li orukọ rẹ̀.
50 Ãnu rẹ̀ si mbẹ fun awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀
lati irandiran.
51 O ti fi agbara hàn li apa rẹ̀; o ti tú
awọn onirera ká ni ironu ọkàn wọn.
52 O ti mu awọn alagbara kuro lori itẹ́
wọn, o si gbé awọn talakà leke.
53 O ti fi ohun ti o dara kún awọn ti
ebi npa; o si rán awọn ọlọrọ̀ pada lọwọ
ofo.
54 O ti ràn Israeli ọmọ-ọdọ rẹ̀ lọwọ, ni
iranti ãnu rẹ̀;
55 Bi o ti sọ fun awọn baba wa, fun
Abrahamu, ati fun irú-ọmọ rẹ̀ lailai.
56 Maria si ba a joko niwọn oṣù mẹta, o
si pada lọ si ile rẹ̀.
57 Ọjọ Elisabeti pe wayi ti yio bí; o si
bí ọmọkọnrin kan.
58 Ati awọn aladugbo, ati awọn ará rẹ̀
gbọ́ bi Oluwa ti ṣe ãnu nla fun u; nwọn si
ba a yọ̀.
59 O si ṣe, ni ijọ kẹjọ nwọn wá lati kọ
ọmọ na nila; nwọn si sọ orukọ rẹ̀ ni Saka-
riah, gẹgẹ bi orukọ baba rẹ̀.
60 Iya rẹ̀ si dahùn, o ni, Bẹ̃kọ; bikoṣe
Johannu li a o pè e.
61 Nwọn si wi fun u pe, Kò si ọkan ninu
awọn ará rẹ ti a npè li orukọ yi.
62 Nwọn si ṣe apẹrẹ si baba rẹ̀, bi o ti
nfẹ ki a pè e.
63 O si bère walã, o kọ, wipe, Johannu
li orukọ rẹ̀. Ẹnu si yà gbogbo wọn.
64 Ẹnu rẹ̀ si ṣí lọgan, okùn ahọn rẹ̀ si
tú, o si sọ̀rọ, o si yìn Ọlọrun.
65 Ẹ̀ru si ba gbogbo awọn ti mbẹ li
àgbegbe wọn: a si ti rò gbogbo ìhin wọnyi
ká gbogbo ilẹ òke Judea.
66 Gbogbo awọn ti o gbọ́ si tò o sinu
ọkàn wọn, nwọn nwipe, Irú ọmọ kili eyi o
jẹ! Ọwọ́ Oluwa si pẹlu rẹ̀.
67 Sakariah baba rẹ̀ si kún fun Ẹmí
Mimọ́, o si sọtẹlẹ, o ni,
68 Olubukun li Oluwa Ọlọrun Israeli;
nitoriti o ti bojuwò, ti o si ti dá awọn enia
rẹ̀ nide,
69 Ti o si ti gbé iwo igbala soke fun wa
ni ile Dafidi ọmọ-ọdọ rẹ̀;
70 Bi o ti wi li ẹnu awọn woli rẹ̀ mimọ́,
ti nwọn ti mbẹ nigbati aiye ti ṣẹ̀:
71 Pe, a o gbà wa là lọwọ awọn ọtá wa,
ati lọwọ gbogbo awọn ti o korira wa;
72 Lati ṣe ãnu ti o ti leri fun awọn baba
wa, ati lati ranti majẹmu rẹ̀ mimọ́;
73 Ara ti o ti bú fun Abrahamu baba
wa,
74 Pe on o fifun wa, lati gbà wa lọwọ
awọn ọtá wa, ki awa ki o le ma sìn i lai-
fòya,
75 Ni mimọ́ ìwa ati li ododo niwaju rẹ̀,
li ọjọ aiye wa gbogbo.
76 Ati iwọ, ọmọ, woli Ọgá-ogo li a o mã
pè ọ: nitori iwọ ni yio ṣaju Oluwa lati tún
ọna rẹ̀ ṣe;

Digitized by Google

77 Lati fi ìmọ igbala fun awọn enia rẹ̀
fun imukuro ẹ̀ṣẹ wọn,
78 Nipa iyọ́nu Ọlọrun wa; nipa eyiti
ìla-õrùn lati oke wá bojuwò wa,
79 Lati fi imọlẹ fun awọn ti o joko li
òkunkun ati li ojiji ikú, ati lati fi ẹsẹ wa
le ọ̀na alafiá.
80 Ọmọ na si dàgba, o si le li ọkàn, o si
wà ni ijù titi o fi di ọjọ ifihàn rẹ̀ fun Israeli.

## ORI 2.

O SI ṣe li ọjọ wọnni, aṣẹ ti ọdọ Kesari
Augustu wá pe, ki a kọ orukọ enia
gbogbo aiye sinu iwe.
2 (Ikọ sinu iwe yi tètekọ bẹ̀rẹ nigbati
Kireniu fi jẹ Bãlẹ Siria.)
3 Gbogbo awọn enia si lọ olukuluku si
ilu ara rẹ̀, lati kọ orukọ rẹ̀ sinu iwe.
4 Josefu pẹlu si rè oke lati Nasareti ilu
ni Galili lọ, si ilu Dafidi ni Judea, ti a npè
ni Betlehemu; (nitoriti o ṣe ti iran ati
idile Dafidi:)
5 Lati kọ orukọ rẹ̀, pẹlu Maria aya rẹ̀
afẹṣọna, ti o tobi fun oyún.
6 O si ṣe, nigbati nwọn wà nibẹ̀, ọjọ rẹ̀
pé ti on o bí.
7 O si bí akọbi rẹ̀ ọmọkọnrin, o si fi ọja
wé e, o si tẹ́ ẹ sinu ibujẹ ẹran; nitoriti àye
kò si fun wọn ninu ile èro.
8 Awọn oluṣọ-agutan mbẹ ni ilu na,
nwọn nṣọ agbo agutan wọn li oru ni pápá
ti nwọn ngbé.
9 Sá si kiyesi i, angeli Oluwa na yọ si
wọn, ati ogo Oluwa si ràn yi wọn ká: ẹ̀ru
si ba wọn gidigidi.
10 Angeli na si wi fun wọn pe, Má bẹ̀ru:
sawò o, mo mu ihin-rere ayọ̀ nla fun nyin
wá, ti yio ṣe ti enia gbogbo.
11 Nitori a bí Olugbala fun nyin loni ni
ilu Dafidi, ti iṣe Kristi Oluwa.
12 Eyi ni yio si ṣe àmi fun nyin; ẹnyin
o ri ọmọ-ọwọ na ti a fi ọja wé, o dubulẹ ni
ibujẹ ẹran.
13 Ọpọlọpọ ogun ọrun si yọ si angeli na
li ojiji, nwọn nyin Ọlọrun, wipe,
14 Ogo ni fun Ọlọrun loke ọrun, ati li
aiye alafia, ifẹ inu rere si enia.
15 O si ṣe, nigbati awọn angẹli na pada
kuro lọdọ wọn lọ si ọrun, awọn ọkọnrin
oluṣọ-agutan na ba ara wọn sọ pe, Ẹ jẹ ki
a lọ si Betlehemu tàra, ki a le ri ohun ti o
ṣẹ, ti Oluwa fihàn fun wa.
16 Nwọn si wá lọgan, nwọn si ri Maria,
ati Josefu, ati ọmọ-ọwọ na, o dubulẹ ninu
ibujẹ ẹran.
17 Nigbati nwọn si ti ri i, nwọn rò ìhin
na kiri ti a ti wi fun wọn nidi ti ọmọ
yi.
18 Ẹnu si yà gbogbo awọn ti o gbọ́ si
nkan wọnyi, ti a ti wi fun wọn lati ọdọ
awọn oluṣọ-agutan wá.
19 Ṣugbọn Maria pa gbogbo nkan wọnyi
mọ́, o nrò wọn ninu ọkàn rẹ̀.
20 Awọn oluṣọ-agutan si pada lọ, nwọn
nfi ogo fun Ọlọrun, nwọn si nyìn i, nitori
ohun gbogbo ti nwọn ti gbọ́ ati ti nwọn ti
ri, bi a ti wi i fun wọn.
21 Nigbati ijọ kẹjọ si pé lati kọ ọmọ na
nila, nwọn pè orukọ rẹ̀ ni JESU, bi a ti sọ
ọ tẹlẹ lati ọdọ angeli na wá ki a to lóyun
rẹ̀ ninu.
22 Nigbati ọjọ iwẹnu rẹ̀ (Maria) si pé
gẹgẹ bi ofin Mose, nwọn gbé e (Jesu) wá si
Jerusalemu lati fi i fun Oluwa;
23 (Bi a ti kọ ọ sinu ofin Oluwa pe,
Gbogbo ọmọ ọkọnrin ti o ṣe akọbi, on li a
o pè ni mimọ́ fun Oluwa;)
24 Ati lati rubọ gẹgẹ bi a ti wi i li ofin
Oluwa, Adaba meji tabi ọmọ ẹiyẹle meji.
25 Si kiyesi i, ọkọnrin kan wà ni Jeru-
salemu, orukọ rẹ̀ a ma jẹ Simeoni; ọkọn-
rin na si ṣe olõtọ ati olufọkànsin, o duro
dè itunu Israeli: Ẹmí Mimọ́ si bà le e.
26 A si ti fihàn a lati ọdọ Ẹmí Mimọ́ na
wá pe, on kì yio ri ikú, ki o to ri Kristi
Oluwa.
27 O si ti ipa Ẹmí wá sinu tempili:
nigbati awọn õbi rẹ̀ si gbé ọmọ na Jesu wá,
lati ṣe fun u bi iṣe ofin,
28 Nigbana li o gbé e li apa rẹ̀, o fi ibu-
kun fun Ọlọrun, o ni,
29 Oluwa, nigbayi li o to jọwọ ọmọ-ọdọ
rẹ lọwọ lọ li alafia, gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ:
30 Nitoriti oju mi ti ri igbala rẹ na,
31 Ti iwọ ti pèse silẹ niwaju enia gbo-
gbo;
32 Imọlẹ lati mọ́ si awọn Keferi, ati ogo
Israeli enia rẹ.
33 Ẹnu si yà Josefu ati iya rẹ̀ si nkan ti
a nsọ si i wọnyi.
34 Simeoni si sure fun wọn, o si wi fun
Maria iya rẹ̀ pe, Kiyesi i, a gbé ọmọ yi
kalẹ fun iṣubu ati idide ọ̀pọ enia ni Israeli;
ati fun àmi ti a o sọ̀rọ òdi si;
35 (Idà yio si gún iwọ na li ọkàn pẹlu,)
ki a le fi ironu ọ̀pọ ọkán hàn.
36 Ẹnikan si mbẹ, Anna woli, ọmọbirin
Fanueli, li ẹ̀ya Aseri: ọjọ ogbó rẹ̀ pọ̀, o ti
ba ọkọ gbé li ọdún meje lati igba wundia
rẹ̀ wá;
37 O si ṣe opó ìwọn ọdún mẹrinlelọgọrin,

Digitized by Google

ẹniti kò kuro ni tempili, o si nfi àwẹ ati
adura sìn Ọlọrun lọsán ati loru.
38 O si wọle li akokò na, o si dupẹ fun
Oluwa pẹlu, o si sọ̀rọ rẹ̀ fun gbogbo awọn
ti o duro dè idande ni Jerusalemu.
39 Nigbati nwọn si ti ṣe nkan gbogbo
tan gẹgẹ bi ofin Oluwa, nwọn pada lọ si
Galili, si Nasareti ilu wọn.
40 Ọmọ na si dàgba, o si le li ọkàn, o si
kún fun ọgbọ́n: ore-ọfẹ Ọlọrun si mbẹ lara
rẹ̀.
41 Awọn õbi rẹ̀ a si ma lọ si Jerusalemu
li ọdọdún si ajọ ọdún irekọja.
42 Nigbati o si di ọmọ ọdún mejila,
nwọn goke lọ si Jerusalemu gẹgẹ bi iṣe ajọ
ọdún na.
43 Nigbati nwọn si pé ọjọ wọn, bi nwọn
ti npada bọ̀, ọmọ na Jesu duro lẹhin ni
Jerusalemu; ati Josefu ati iya rẹ̀ kò mọ̀.
44 Ṣugbọn nwọn ṣebi o wà li ẹgbẹ èro,
nwọn rìn ìrin ọjọ kan; nwọn wá a kiri ni-
nu awọn ará ati awọn ojulumọ̀ wọn.
45 Nigbati nwọn kò si ri i, nwọn tún
pada si Jerusalemu, nwọn nwá a kiri.
46 O si ṣe, ni ijọ kẹta nwọn ri i ninu
tempili o joko li arin awọn olukọni, o ngbọ́
ti wọn, o si mbi wọn lẽre.
47 Ẹnu si yà gbogbo awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ
rẹ̀ li oyé ati idahùn rẹ̀.
48 Nigbati nwọn si ri i, hà ṣe wọn: iya
rẹ̀ si bi i pe, Ọmọ, ẽṣe ti iwọ fi ṣe wa bẽ?
sawò o, baba rẹ ati emi ti nfi ibinujẹ wá ọ
kiri.
49 O si dahùn wi fun wọn pe, Ẽṣe ti
ẹnyin fi nwá mi kiri? ẹnyin kò mọ̀ pe, emi
kò le ṣàima wà nibi iṣẹ baba mi?
50 Ọ̀rọ ti o sọ kò si yé wọn.
51 O si ba wọn sọkalẹ lọ si Nasareti, o
si fi ara balẹ fun wọn: ṣugbọn iya rẹ̀ pa
gbogbo nkan wọnyi mọ́ ninu ọkàn rẹ̀.
52 Jesu si pọ̀ li ọgbọ́n, o si ndàgba, o si
wà li oju rere li ọdọ Ọlọrun ati enia.

## ORI 3.

LI ọdún kẹdogun ijọba Tiberiu Kesari,
nigbati Pontiu Pilatu jẹ Bãlẹ Judea,
ti Herodu si jẹ tetrarki Galili, Filippi ara-
kọnrin rẹ̀ si jẹ tetrarki Iturea ati ti Trakon-
iti, Lisania si jẹ tetrarki Abilene,
2 Ti Anna on Kaiafa nṣe olori awọn
alufa, nigbana li ọ̀rọ Ọlọrun tọ̀ Johannu
ọmọ Sakariah wá ni ijù.
3 O si wá si gbogbo ilẹ ìha Jordani, o
nwasu baptismu ironupiwada fun imukuro
ẹ̀ṣẹ;
4 Bi a ti kọ ọ ninu iwe ọ̀rọ woli Isaiah
pe, Ohùn ẹni ti nkigbe ni ijù, Ẹ tún ọ̀na
Oluwa ṣe, ẹ mu ipa-ọna rẹ̀ tọ́.
5 Gbogbo ọgbún li a o kún, gbogbo òke
nla ati òke kekere li a o tẹ-bẹrẹ; wíwọ li a
o ṣe ni títọ, ati ọ̀na palapala li a o sọ di
kikuna;
6 Gbogbo enia ni yio si ri igbala Ọlọrun.
7 Nigbana li o wi fun ọ̀pọ awọn enia ti
o wá lati baptisi lọdọ rẹ̀ pe, Ẹnyin iran
paramọlẹ, tali o kìlọ fun nyin lati sá kuro
ninu ibinu ti mbọ̀?
8 Njẹ ki ẹnyin ki o so eso ti o yẹ fun
ironupiwada, ki ẹ má si ṣe bẹ̀rẹ si iwi ninu
ara nyin pe, awa ni Abrahamu ni baba:
ki emi ki o wi fun nyin, Ọlọrun le gbe
ọmọ dide fun Abrahamu ninu okuta
wọnyi.
9 Ati nisisiyi pẹlu, a fi ãke le gbòngbo
igi na: gbogbo igi ti kò ba so eso rere, a
ke e lulẹ, a si wọ́ ọ jù sinu iná.
10 Awọn enia si mbi i pe, Kini ki awa
ki o ha ṣe?
11 O dahùn o si wi fun wọn pe, Ẹniti o
ba li ẹ̀wu meji, ki o fi ọkan fun ẹniti kò
ni; ẹniti o ba si li onjẹ, ki o ṣe bẽ pẹlu.
12 Nigbana li awọn agbowode tọ̀ ọ wá
lati baptisi lọdọ rẹ̀, nwọn si bi i pe, Olu-
kọni, kili awa o ha ṣe?
13 O si dahùn o wi fun wọn pe, Ẹ máṣe
gbà jù bi ati rán nyin lọ mọ́.
14 Awọn ọmọ-ọgun si bère lọdọ rẹ̀, wipe,
Kili awa o ṣe? O si wi fun wọn pe, Ẹ
máṣe ẹnikẹni ni jamba, bẽni ki ẹ má si
gbà dulumọ ẹnikan; ki owo onjẹ nyin ki
o si kún nyin loju.
15 Bi awọn enia si ti nreti, ti gbogbo
wọn si nrò ninu ara wọn nitori Johannu,
bi on ni Kristi bi on kọ́;
16 Johannu dahùn o si wi fun gbogbo
wọn pe, Lõtọ li emi nfi omi baptisi nyin;
ṣugbọn ẹniti o pọ̀ju mi lọ mbọ̀, okùn bàta
ẹsẹ ẹniti emi kò to itú: on ni yio fi Ẹmí
Mimọ́ ati iná baptisi nyin:
17 Ẹniti atẹ rẹ̀ mbẹ li ọwọ́ rẹ̀, yio si gbá
ilẹ ipaka rẹ̀ mọ́ toto, yio si kó alikama rẹ̀
sinu aká; ṣugbọn ìyangbo ni yio fi iná
ajõku sun.
18 Ohun pipọ pẹlu li o si wasu fun
awọn enia ni ìkilọ rẹ̀.
19 Ṣugbọn Herodu tetrarki, ti o bawi
nitori Herodia aya Filippi arakọnrin rẹ̀,
ati itori ohun buburu gbogbo ti Herodu ti
ṣe,
20 O fi eyi pari gbogbo rẹ̀ niti ti o fi
Johannu sinu tubu.

Digitized by Google

21 Nigbati a si baptisi awọn enia gbo-
gbo tan, o si ṣe, a baptisi Jesu pẹlu, bi o ti
ngbadura, ọrun ṣí silẹ,
22 Ẹmí Mimọ́ si sọkalẹ si ori rẹ̀ li àwọ
àdaba, ohùn kan si ti ọrun wá, ti o wipe,
Iwọ ni ayanfẹ ọmọ mi; ẹniti inu mi dùn
si gidigidi.
23 Jesu tikararẹ̀ nto bi ẹni ìwọn ọgbọ̀n
ọdún, o jẹ (bi a ti fi pè) ọmọ Josefu, ti iṣe
ọmọ Eli,
24 Ti iṣe ọmọ Mattati, ti iṣe ọmọ Lefi,
ti iṣe ọmọ Melki, ti iṣe ọmọ Janna, ti iṣe
ọmọ Josefu,
25 Ti iṣe ọmọ Mattatia, ti iṣe ọmọ
Amosi, ti iṣe ọmọ Naumu, ti iṣe ọmọ Esli,
ti iṣe ọmọ Naggai,
26 Ti iṣe ọmọ Maati, ti iṣe ọmọ Mat-
tatia, ti iṣe ọmọ Ṣimei, ti iṣe ọmọ Josefu,
ti iṣe ọmọ Juda,
27 Ti iṣe ọmọ Joanna, ti iṣe ọmọ Resa,
ti iṣe ọmọ Sorobabeli, ti iṣe ọmọ Salatieli,
ti iṣe ọmọ Neri,
28 Ti iṣe ọmọ Melki, ti iṣe ọmọ Addi,
ti iṣe ọmọ Kosamu, ti iṣe ọmọ Elmodamu,
ti iṣe ọmọ Eri,
29 Ti iṣe ọmọ Jose, ti iṣe ọmọ Elieseri,
ti iṣe ọmọ Jorimu, ti iṣe ọmọ Mattati, ti
iṣe ọmọ Lefi,
30 Ti iṣe ọmọ Simeoni, ti iṣe ọmọ Juda,
ti iṣe ọmọ Josefu, ti iṣe ọmọ Jonani, ti iṣe
ọmọ Eliakimu,
31 Ti iṣe ọmọ Melea, ti iṣe ọmọ Menani,
ti iṣe ọmọ Mattata, ti iṣe ọmọ Natani, ti
iṣe ọmọ Dafidi,
32 Ti iṣe ọmọ Jesse, ti iṣe ọmọ Obedi, ti
iṣe ọmọ Boasi, ti iṣe ọmọ Solmoni, ti iṣe
ọmọ Naassoni,
33 Ti iṣe ọmọ Aminadabu, ti iṣe ọmọ
Aramu, ti iṣe ọmọ Esromu, ti iṣe ọmọ
Faresi, ti iṣe ọmọ Juda,
34 Ti iṣe ọmọ Jakọbu, ti iṣe ọmọ Isaaki,
ti iṣe ọmọ Abrahamu, ti iṣe ọmọ Tera, ti
iṣe ọmọ Nakoru,
35 Ti iṣe ọmọ Saruku, ti iṣe ọmọ Ragau,
ti iṣe ọmọ Faleki, ti iṣe ọmọ Eberi, ti iṣe
ọmọ Sala,
36 Ti iṣe ọmọ Kainani, ti iṣe ọmọ Arfak-
sadi, ti iṣe ọmọ Semu, ti iṣe ọmọ Noa, ti
iṣe ọmọ Lameki,
37 Ti iṣe ọmọ Metusala, ti iṣe ọmọ
Enoku, ti iṣe ọmọ Jaredi, ti iṣe ọmọ Male-
leeli, ti iṣe ọmọ Kainani,
38 Ti iṣe ọmọ Enosi, ti iṣe ọmọ Seti, ti
iṣe ọmọ Adamu, ti iṣe ọmọ Ọlọrun.

## ORI 4.

JESU si kún fun Ẹmí Mimọ́, o pada ti
Jordani wá, a si ti ọwọ́ Ẹmí dari rẹ̀ si
ijù,
2 Ogoji ọjọ li a fi dán a wò lọwọ Èṣu.
Kò si jẹ ohunkohun li ọjọ wọnni: nigbati
nwọn pé, lẹhin na li ebi wa npa a.
3 Èṣu si wi fun u pe, Bi iwọ ba ṣe Ọmọ
Ọlọrun, paṣẹ fun okuta yi ki o di akara.
4 Jesu si dahùn wi fun u pe, A ti kọwe
rẹ̀ pe, Enia kò wà nipa akara nikan, bikoṣe
nipa gbogbo ọ̀rọ Ọlọrun.
5 Èṣu si mu u re ori òke giga, o si fi
gbogbo ilẹ ọba aiye hàn a nigba iṣẹju kan.
6 Èṣu si wi fun u pe, Gbogbo agbara
wọnyi li emi o fifun ọ, ati ogo wọn: gbo-
gbo rẹ̀ li a sá fifun mi; ẹnikẹni ti o ba si
wù mi, emi a fi i fun.
7 Njẹ bi iwọ ba foribalẹ fun mi, gbogbo
rẹ̀ ni yio ṣe tirẹ.
8 Jesu si dahùn o si wi fun u pe, Kuro
lẹhin mi, Satani; nitoriti a kọwe rẹ̀ pe,
Ki iwọ ki o ma foribalẹ fun Oluwa Ọlọrun
rẹ, on nikanṣoṣo ni ki iwọ ki o si ma sìn.
9 O si mu u lọ si Jerusalemu, o si gbé e
kà ipari tempili, o si wi fun u pe, Bi iwọ
ba ṣe Ọmọ Ọlọrun, bẹ́ silẹ lati ihinyi lọ:
10 A sá ti kọwe rẹ̀ pe, Yio kilọ fun
awọn angeli rẹ̀ nitori rẹ̀, lati ma ṣe itọju
rẹ:
11 Li ọwọ́ wọn ni nwọn o si gbé ọ soke,
ki iwọ ki o má ba fi ẹsẹ rẹ gbún okuta.
12 Jesu si dahùn o wi fun u pe, A ti sọ
pe, Iwọ kò gbọdọ dán Oluwa Ọlọrun rẹ
wò.
13 Nigbati Èṣu si pari idanwò na gbo-
gbo, o fi i silẹ lọ digboṣe.
14 ¶ Jesu si fi agbara Ẹmí pada wá si
Galili: okikí rẹ̀ si kàn kalẹ ni gbogbo
àgbegbe ti o yiká.
15 O si nkọni ninu sinagogu wọn, a
nyìn i logo lati ọdọ gbogbo awọn enia wá.
16 ¶ O si wá ni Nasareti, nibiti a gbé ti
tọ́ ọ dàgba: bi iṣe rẹ̀ ti ri, o si wọ̀ inu
sinagogu lọ li ọjọ isimi, o dide lati kàwe.
17 A si fi iwe woli Isaiah fun u. Ni-
gbati o si ṣí iwe na, o ri ibiti a gbé kọ ọ pe,
18 Ẹmi Oluwa mbẹ lara mi, nitoriti o fi
àmi oróro yàn mi lati wasu Ihinrere fun
awọn òtoṣi; o ti rán mi wá lati ṣe awotan
awọn onirobinujẹ ọkàn, lati wasu idasilẹ
fun awọn igbekun, itunriran fun awọn
afọju, ati lati jọwọ awọn ti a pa lara lọwọ,
19 Lati wasu ọdún itẹwọgba Oluwa.
20 O si pa iwe na de, o tun fi i fun iranṣẹ,

Digitized by Google

o si joko. Gbogbo awọn ti o mbẹ ninu
sinagogu si tẹjumọ ọ.
21 O si bẹrẹ si iwi fun wọn pe, Loni ni
Iwe mimọ́ yi to ṣẹ li etí nyin.
22 Gbogbo wọn si jẹri rẹ̀, hà si ṣe wọn
si ọ̀rọ rere ti njade li ẹnu rẹ̀. Nwọn si
nwipe, Ọmọ Josefu kọ yi?
23 O si wi fun wọn pe, Lõtọ li ẹnyin o
pa owe yi si mi pe, Oniṣegun, wò ara rẹ
da: ohunkohun ti awa gbọ́ pe o ti ọwọ́ rẹ
ṣe ni Kapernaumu, ṣe e nihinyi ni ilẹ baba
rẹ pẹlu.
24 O si wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin,
Kò si woli ti a tẹwọgbà ni ilẹ baba rẹ̀.
25 Ṣugbọn mo wi fun nyin nitõtọ, opó
pipọ li o wà ni Israeli nigba ọjọ woli Elijah,
nigbati ọrun fi sé li ọdún mẹta on oṣù mẹfa,
nigbati ìyan nla fi mu ká ilẹ gbogbo;
26 Kò si ẹniti a rán Elijah si, bikoṣe si
obirin opó kan ni Sarefati, ilu kan ni
Sidoni.
27 Ati adẹtẹ̀ pipọ ni mbẹ ni Israeli nigba
woli Eliṣa; kò si ẹniti a wẹnumọ́ ninu
wọn, bikoṣe Naamani ara Siria.
28 Nigbati gbogbo awọn ti o wà ninu
sinagogu gbọ́ nkan wọnyi, inu ru wọn
ṣùṣù.
29 Nwọn si dide, nwọn tì i sode si ẹhin
ilu, nwọn si fà a lọ si bèbe òke nibiti nwọn
gbé tẹ̀ ilu wọn do, ki nwọn ki o le tari rẹ̀
li ogedengbe.
30 Ṣugbọn o kọja larin wọn, o ba tirẹ̀ lọ.
31 O si sọkalẹ wá si Kapernaumu, ilu
kan ni Galili, o si nkọ́ wọn li ọjọ isimi.
32 Ẹnu si yà wọn si ẹkọ́ rẹ̀: nitori
ikánilara pẹlu ọ̀rọ rẹ̀.
33 ¶ Ọkọnrin kan si wà ninu sinagogu,
ẹniti o li ẹmi aimọ́, o kigbe li ohùn rara,
34 O ni, Jọwọ wa jẹ; kini ṣe tawa tirẹ,
Jesu ara Nasareti? iwọ wá lati pa wa run?
emi mọ̀ ẹniti iwọ iṣe; Ẹni Mimọ́ Ọlọrun.
35 Jesu si ba a wi, o ni, Pa ẹnu rẹ mọ́,
ki o si jade lara rẹ̀. Nigbati ẹmi eṣu na si
gbé e ṣanlẹ li awujọ, o jade kuro lara rẹ̀,
kò si pa a lara.
36 Hà si ṣe gbogbo wọn, nwọn si mba
ara wọn sọ, wipe, Ọ̀rọ kili eyi! nitori aṣẹ
on agbara li o fi ba awọn ẹmi aimọ́ wi,
nwọn si jade kuro.
37 Okikí rẹ̀ si kàn nibi gbogbo li àgbe-
gbe ilẹ na yiká.
38 ¶ Nigbati o si dide kuro ninu sina-
gogu, o si wọ̀ ile Simoni lọ; ibà si ti dá
iya aya Simoni bulẹ; nwọn si bẹ̀ ẹ nitori
rẹ̀.
39 O si duro tirisi i o ba ibà na wi;
ibà si jọwọ rẹ̀ lọwọ: o si dide lọgan o nṣe
iranṣẹ fun wọn.
40 ¶ Nigbati õrùn si nwọ̀, gbogbo awọn
ẹniti o ni olokunrun ti o li arunkarun,
nwọn mu wọn tọ̀ ọ wá; o si fi ọwọ́ le olu-
kuluku wọn, o si mu wọn lara da.
41 Awọn ẹmi eṣu si jade lara ẹni pipọ
pẹlu, nwọn nkigbe, wipe, Iwọ ni Kristi
Ọmọ Ọlọrun. O si mba wọn wi, kò jẹ ki
nwọn ki o fọhun: nitoriti nwọn mọ̀ pe
Kristi ni iṣe.
42 Nigbati ilẹ mọ́, o dide lọ si ibi ijù:
ijọ enia si nwá a kiri, nwọn si tọ̀ ọ wá,
nwọn si da a duro, nitori ki o má ba lọ
kuro lọdọ wọn.
43 O si wi fun wọn pe, Kò yẹ ki emi mã
wasu ijọba Ọlọrun fun ilu miran pẹlu:
nitorina li a sá ṣe rán mi.
44 O si wasu ninu sinagogu ti Galili.

## ORI 5.

O SI ṣe, nigbati ọ̀pọ enia ṣù mọ́ ọ lati gbọ́
ọ̀rọ Ọlọrun, ti o si duro leti adagun
Genesareti,
2 O si ri ọkọ meji ti nwọn gún leti ada-
gun: ṣugbọn awọn apẹja sọkalẹ kuro ninu
wọn, nwọn nfọ̀ àwọn wọn.
3 O si wọ̀ ọkan ninu awọn ọkọ̀ na, ti iṣe
ti Simoni, o si bẹ̀ ẹ ki o tẹ̀ si ẹhin diẹ kuro
ni ilẹ. O si joko, o si nkọ́ ọ̀pọ enia lati
inu ọkọ̀ lọ.
4 Bi o ti dakẹ ọ̀rọ isọ, o wi fun Simoni
pe, Tì si ibu, ki o si jù àwọn nyin si isalẹ
fun akopọ̀.
5 Simoni dahùn o si wi fun u pe, Olu-
kọni, gbogbo oru aná li awa fi ṣiṣẹ, awa kò
si mu nkan: ṣugbọn nitori ọ̀rọ rẹ emi o jù
àwọn na si isalẹ.
6 Nigbati nwọn si ti ṣe eyi, nwọn kó
ọ̀pọ ẹja: àwọn wọn si ya.
7 Nwọn si ṣapẹrẹ si ẹgbẹ wọn, ti o wà li
ọkọ̀ keji, ki nwọn ki o wá lati ràn wọn
lọwọ. Nwọn si wá, nwọn si kún ọkọ̀ me-
jeji, bẹ̃ni nwọn bẹrẹ si irì.
8 Nigbati Simoni Peteru ri i, o wolẹ
lẹba ẽkun Jesu, o wipe, Lọ kuro lọdọ mi;
nitori ẹlẹṣẹ ni mi, Oluwa.
9 Hà si ṣe e, ati gbogbo awọn ti mbẹ
pẹlu rẹ̀, fun akopọ̀ ẹja ti nwọn kó:
10 Bẹ̃ si ni Jakọbu ati Johannu awọn
ọmọ Sebede, ti nṣe alabapa Simoni. Jesu
si wi fun Simoni pe, Máṣe bẹru; lati isisiyi
lọ iwọ o mu enia.
11 Nigbati nwọn si ti mu ọkọ̀ wọn de
ilẹ, nwọn fi gbogbo rẹ̀ silẹ, nwọn si tọ̀ ọ
lẹhin lọ.

Digitized by Google

12 ¶ O si ṣe, nigbati o wọ̀ ilu kan, ki-
yesi i, ọkọnrin kan ti ẹ̀tẹ bò: nigbati o ri
Jesu, o wolẹ, o si mbẹ̀ ẹ, wipe, Oluwa, bi
iwọ ba fẹ, iwọ le sọ mi di mimọ́.
13 O si nà ọwọ́ rẹ, o tọ́ ọ lara, o ni, Mo
fẹ: ki iwọ ki o mọ́. Lọgan ẹ̀tẹ si fi i silẹ
lọ.
14 O si kìlọ fun u pe, ki o máṣe sọ fun
ẹnikan: ṣugbọn ki o lọ, ki o si fi ara rẹ
hàn fun alufa, ki o si ta ọrẹ fun iwẹnu-
mọ́ rẹ, gẹgẹ bi Mose ti sọ ọ niti ẹrí fun
wọn.
15 Ṣugbọn si iwaju li okikí rẹ̀ nkàn
kalẹ: ọ̀pọ enia si jumọ pade lati gbọ́ ọ̀rọ
rẹ̀, ati lati gbà dida ara lọdọ rẹ̀ kuro lọwọ
ailera wọn.
16 ¶ O si yẹ̀ ara si ijù, o si gbadura.
17 O si ṣe ni ijọ kan, bi o si ti nkọ́ni,
awọn Farisi, on awọn amofin joko ni ìha
ibẹ̀, nwọn ti ilu Galili gbogbo, ati Judea,
ati Jerusalemu wá: agbara Oluwa si mbẹ
lati mu wọn lara da.
18 ¶ Sá si kiyesi i, awọn ọkọnrin gbé
ọkọnrin kan ti ẹ̀gba nṣe wá lori akete:
nwọn nwá ọ̀na ati gbé e wọle, ki nwọn ki
o si tẹ́ ẹ siwaju rẹ̀.
19 Nigbati nwọn kò si ri ọ̀na ti nwọn
iba fi gbé e wọle nitori ọ̀pọ enia, nwọn gùn
oke àja ile lọ, nwọn sọ̀ ọ kalẹ li alafo àja ti
on ti akete rẹ̀ larin niwaju Jesu.
20 Nigbati o si ri igbagbọ́ wọn, o wi fun
u pe, Ọkọnrin yi, a dari ẹ̀ṣẹ rẹ jì ọ.
21 Awọn akọwe ati awọn Farisi bẹ̀rẹ si
igbèrò, wipe, Tali eyi ti nsọ ọ̀rọ buburu si
Ọlọrun? tali o le dari ẹ̀ṣẹ jìni bikoṣe Ọlọrun
nikanṣoṣo?
22 Ṣugbọn nigbati Jesu mọ̀ ìro inu wọn,
o dahùn o si wi fun wọn pe, Kili ẹnyin nrò
ninu ọkàn nyin?
23 Ewo li o ya jù, lati wipe, A dari ẹ̀ṣẹ
rẹ jì ọ; tabi lati wipe, Dide ki iwọ ki o si
ma rìn?
24 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe, Ọmọ
enia li agbara li aiye lati dari ẹ̀ṣẹ jìni, (o
wi fun ẹlẹgba na pe,) Mo wi fun ọ, Dide, si
gbé akete rẹ nilẹ, ki o si lọ si ile rẹ.
25 O si dide lọgan niwaju wọn, o gbé
ohun ti o dubulẹ le, o si lọ si ile rẹ̀, o nyìn
Ọlọrun logo.
26 Ẹnu si yà wọn, nwọn si nyìn Ọlọrun
logo, ẹ̀ru si ba gbogbo wọn, nwọn nwipe,
Awa ri èmọ loni.
27 ¶ Lẹhin nkan wọnyi li o si lọ, o
si ri agbowode kan, ti a npè ni Lefi, o
joko ni bode: o si wi fun u pe, Mã tọ̀ mi
lẹhin.
28 O si fi gbogbo nkan silẹ, o dide, o si
ntọ̀ ọ lẹhin.
29 Lefi si se àse nla fun u ni ile rẹ̀: ọ̀pọ
awọn agbowode, ati awọn ẹlomiran mbẹ
nibẹ̀ ti nwọn ba wọn joko.
30 Ṣugbọn awọn akọwe, ati awọn Farisi
nkùn si awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, wipe, Ẽṣe ti
ẹnyin fi mbá awọn agbowode ati awọn ẹlẹṣẹ
jẹ, ti ẹ mba wọn mu.
31 Jesu dahùn o si wi fũn wọn pe, Awọn
ti ara wọn le kò wá oniṣegun, bikoṣe awọn
ti ara wọn kò da.
32 Emi kò wá ipè awọn olododo, bikoṣe
awọn ẹlẹṣẹ si ironupiwada.
33 ¶ Nwọn si bi i pe, Ẽṣe ti awọn ọmọ-
ẹhin Johannu fi ngbàwẹ nigbakugba, nwọn
a si ma gbadura, gẹgẹ bẽ̃ si ni awọn ọmọ-
ẹhin awọn Farisi; ṣugbọn awọn tirẹ njẹ,
nwọn nmu?
34 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin le mu ki
awọn ọmọ ile iyawo gbàwẹ, nigbati ọkọ
iyawo mbẹ lọdọ wọn?
35 Ṣugbọn ọjọ mbọ̀ nigbati a o gbà ọkọ
iyawo lọwọ wọn, nigbana ni nwọn o si
gbàwẹ ni ijọ wọnni.
36 ¶ O si pa owe kan fun wọn pe, Kò si
ẹniti imu idãsa aṣọ titun ti isi fi dí ogbolo-
gbo ẹ̀wu; bikoṣepe titun fà a ya, ogbologbo
aṣọ kò ba idãsa titun rẹ́ pọ̀.
37 Kò si si ẹniti ifi ọti-waini titun sinu
ogbologbo ìgo; bikoṣepe ọti-waini titun bẹ́
ìgo na, a si danù, ìgo a si bajẹ.
38 Ṣugbọn ọti-waini titun li a ifi sinu
ìgo titun; awọn mejeji a si ṣe dede.
39 Kò si ẹniti imu ọdá ọti-waini tan, ti
o si fẹ òjò lojukanna: nitoriti o ni, ọdá
san jù.

## ORI 6.

O SI ṣe li ọjọ isimi keji lẹhin ti ekini,
Jesu kọja larin oko ọkà: awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ si nya ipẹ́ ọkà, nwọn nfi ọwọ́ ra a
jẹ.
2 Awọn kan ninu awọn Farisi si bi wọn
pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi nṣe eyi ti kò yẹ lati ṣe li
ọjọ isimi?
3 Jesu si da wọn li ohùn, wipe, Ẹnyin
kò kawe to bi eyi, bi Dafidi ti ṣe, nigbati
ebi npa on tikararẹ̀ ati awọn ti o wà lọdọ
rẹ̀;
4 Bi o ti wọ̀ ile Ọlọrun lọ, ti o si mu
akara ifihàn ti o jẹ, ti o si fifun awọn ti
mbẹ lọdọ rẹ̀ pẹlu; ti kò yẹ fun u lati jẹ,
bikoṣe fun awọn alufa nikanṣoṣo?
5 O si wi fun wọn pe, Ọmọ-enia li Oluwa
ọjọ isimi pẹlu.

Digitized by Google

6 O si ṣe li ọjọ isimi kan pẹlu, ti o wọ̀
inu sinagogu lọ, o si nkọ́ni: ọkọnrin kan
si mbẹ nibẹ̀ ti ọwọ́ rẹ̀ ọtún rọ.
7 Ati awọn akọwe ati awọn Farisi nṣọ ọ,
bi yio mu u lara da li ọjọ isimi; ki nwọn
ki o le ri ọna ati fi i sùn.
8 Ṣugbọn o mọ̀ ìro inu wọn, o si wi fun
ọkọnrin na ti ọwọ́ rẹ̀ rọ pe, Dide, ki o si
duro lãrin. O si dide duro.
9 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, Emi
o bi nyin lẽre kan; O tọ́ lati mã ṣe ore li
ọjọ isimi, tabi lati mã ṣe buburu? lati gbà
ẹmí là, tabi lati pa a run?
10 Nigbati o si wò gbogbo wọn yiká, o
wi fun ọkọnrin na pe, Nà ọwọ́ rẹ. O si ṣe
bẹ̃: ọwọ́ rẹ̀ si pada bọ̀ sipò gẹgẹ bi ekeji.
11 Inu wọn si kun fun ibinu; nwọn
si ba ara wọn rò ohun ti awọn iba ṣe si
Jesu.
12 O si ṣe ni ijọ wọnni, o lọ si ori òke
lọ igbadura, o si fi gbogbo oru na gbadura
si Ọlọrun.
13 ¶ Nigbati ilẹ si mọ́, o nahùn pè awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀ sọdọ rẹ̀: ninu wọn li o si yàn
mejila, ti o si sọ ni Aposteli;
14 Simoni, (ẹniti o si sọ ni Peteru,) ati
Anderu arakọnrin rẹ̀, Jakọbu ati Johannu,
Filippi ati Bartolomeu,
15 Matteu ati Tomasi, Jakọbu ọmọ
Alfeu, ati Simoni ti a npè ni Selote,
16 Ati Juda arakọnrin Jakọbu, ati Ju-
dasi Iskariotu ti iṣe onikupani.
17 ¶ O si ba wọn sọkalẹ, o si duro ni
gbangba, ati ọ̀pọ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, ati
ijọ enia pipọ ti o jade, lati gbogbo Judea,
ati Jerusalemu wá, ati àgbegbe Tire on
Sidoni, nwọn tọ̀ ọ wá lati gbọ́ ọ̀rọ lọdọ
rẹ̀, ati lati wá gbà dida ara kuro ninu arùn
wọn;
18 Ati awọn ti ara kan fun ẹmi aimọ́: a
si mu wọn lara da.
19 Gbogbo ijọ enia si nfẹ fi ọwọ́ kàn a;
nitoriti aṣẹ njade lara rẹ̀, o si mu gbogbo
wọn lara da.
20 ¶ Nigbati o si gbé oju rẹ̀ soke si awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀, o ni, Alabukun-fun li ẹnyin
òtoṣi: nitori ti nyin ni ijọba Ọlọrun.
21 Alabukun-fun li ẹnyin alaiyó nisisiyi:
nitoriti a o fi onjẹ kún nyin. Alabukun-
fun li ẹnyin ẹlẹkún isisiyi: nitoriti ẹnyin
o rẹrin.
22 Alabukun-fun li ẹnyin, nigbati awọn
enia ba nkorira nyin, ti nwọn ba nyà nyin
kuro ninu ẹgbẹ wọn, ti nwọn ba ngàn nyin,
ti nwọn ba nta orukọ nyin nù ni buburu,
nitori Ọmọ-enia.
23 Ki ẹnyin ki o yọ̀ ni ijọ na, ki ẹnyin
ki o si fò soke fun ayọ̀: sá wò o, ère nyin
pọ̀ li ọrun: nitori bẹ̃ gẹgẹ li awọn baba
wọn ṣe si awọn woli.
24 Ṣugbọn egbé ni fun ẹnyin ọlọrọ̀!
nitoriti ẹnyin ti ri irọra nyin na.
25 Egbé ni fun ẹnyin ti o yó! nitoriti
ebi yio pa nyin. Egbé ni fun ẹnyin ti
nrẹrin nisisiyi! nitoriti ẹnyin o gbàwẹ,
ẹnyin o si sọkun.
26 Egbé ni fun nyin, nigbati gbogbo
enia ba nsọ̀rọ nyin ni rere! nitori bẹ̃ gẹgẹ
li awọn baba wọn ṣe si awọn eke woli.
27 ¶ Ṣugbọn mo wi fun ẹnyin ti ngbọ́, Ẹ
fẹ awọn ọtá nyin, ṣore fun awọn ti nkorira
nyin.
28 Sure fun awọn ti nfi nyin ré, si gba-
dura fun awọn ti nkẹgan nyin.
29 Ẹniti o ba si lù iwọ li ẹrẹkẹ kan, pa
ekeji dà si i pẹlu; ati ẹniti o gbà agbada
rẹ, máṣe da a duro lati gbà tòro rẹ pẹlu.
30 Si fifun gbogbo ẹniti o tọrọ lọdọ rẹ;
lọdọ ẹniti o si kó ọ li ẹrù, má si ṣe pada
bère.
31 Gẹgẹ bi ẹnyin si ti fẹ ki enia ki o
ṣe si nyin, ki ẹnyin ki o si ṣe bẹ̃ si wọn
pẹlu.
32 Njẹ bi ẹnyin ba fẹ awọn ti o fẹ nyin,
ọpẹ́ kili ẹnyin ni? awọn ẹlẹṣẹ pẹlu nfẹ́
awọn ti o fẹ wọn.
33 Bi ẹnyin si ṣore fun awọn ti o ṣore
fun nyin, ọpẹ́ kili ẹnyin ni? awọn ẹlẹṣẹ
pẹlu nṣe bẹ̃ gẹgẹ.
34 Bi ẹnyin si win wọn ni nkan lọwọ
ẹniti ẹnyin o reti ati rigbà pada, ọpẹ́ kili
ẹnyin ni? awọn ẹlẹṣẹ pẹlu nwin ẹlẹṣẹ, ki
nwọn ki o le gbà iwọn bẹ̃ pada.
35 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o fẹ awọn ọtá
nyin, ki ẹnyin ki o si ṣore, ki ẹnyin ki o si
win-ni, ki ẹnyin ki o máṣe reti ati ri nkan
gbà pada; ère nyin yio si pọ̀, awọn ọmọ
Ọgá-ogo li a o si ma pè nyin: nitoriti o
ṣeun fun alaimore ati fun ẹni-buburu.
36 Njẹ ki ẹnyin ki o li ãnu, gẹgẹ bi
Baba nyin si ti li ãnu.
37 Ẹ máṣe dani li ẹjọ, a kì yio si da
nyin li ẹjọ: ẹ máṣe dani li ẹbi, a kì yio si
da nyin li ẹbi: ẹ darijì, a o si darijì nyin:
38 Ẹ fifun ni, a o si fifun nyin; oṣuwọn
daradara, akìmọlẹ, ati amìpọ, akún-wọ-
silẹ, li a o wọ̀n si àiya nyin: nitori oṣu-
wọn na ti ẹnyin fi wọ̀n, on li a o pada fi
wọ̀n fun nyin.
39 O si pa owe kan fun wọn, Afọju le
ṣe amọ̀na afọju? awọn mejeji kì yio ṣubu
sinu ihò?

Digitized by Google

40 Ẹniti a nkọ́ ki ijù olukọ́ rẹ̀ lọ: ṣu-
gbọn olukuluku ẹniti o pé, yio dabi olukọ́
rẹ̀.
41 Eṣe ti iwọ si nwò ẹrún igi ti mbẹ li
oju arakọnrin rẹ, ṣugbọn iwọ kò kiyesi ìti
igi ti mbẹ li oju ara rẹ?
42 Tabi iwọ o ti ṣe le wi fun arakọnrin
rẹ pe, Arakọnrin, jẹ ki emi ki o yọ ẹrún
igi ti mbẹ li oju rẹ, nigbati iwọ tikararẹ
kò kiyesi ìti igi ti mbẹ li oju ara rẹ? iwọ
agabagebe, tètekọ yọ ìti igi jade kuro li
oju ara rẹ na, nigbana ni iwọ o si to riran
gbangba lati yọ ẹrún igi kuro ti mbẹ li oju
arakọnrin rẹ.
43 Nitori igi rere kì iso eso buburu;
bẹ̃ni igi buburu kì iso eso rere.
44 Olukuluku igi li a ifi eso rẹ̀ mọ̀: ni-
tori lori ẹgún oṣuṣu, enia kì iká eso ọpọtọ,
bẹ̃ni lori ẹgún ọgàn a kì iká eso ajara.
45 Enia rere lati inu iṣura rere àiya rẹ̀
ni imu ohun rere jade wá; ati enia bu-
buru lati inu iṣura buburu àiya rẹ̀ ni imu
ohun buburu jade wá: nitori ninu ọ̀pọlọpọ
ohun inu li ẹnu isọ.
46 ¶ Esitiṣe ti ẹnyin npè mi li Oluwa,
Oluwa, ti ẹnyin kò si ṣe ohun ti mo wi?
47 Ẹnikẹni ti o tọ̀ mi wá, ti o si ngbọ́
ọ̀rọ mi, ti o si nṣe e, emi o fi ẹniti o jọ
hàn nyin:
48 O jọ ọkọnrin ti o kọ́ ile kan, ti o si
walẹ jìn, ti o si fi ipilẹ sọlẹ lori apata:
nigbati kíkun omi de, igbi-omi bilù ile na
titi, kò si le mì i: nitoriti a fi ipilẹ rẹ̀ sọlẹ
lori apata.
49 Ṣugbọn ẹniti o gbọ́, ti kò si ṣe, o
dabi ọkọnrin ti o kọ́ ile ni ilẹ laini ipilẹ;
nigbati igbi-omi bilù u titi, lọgan o si wó;
iwó ile na si pọ̀.

## ORI 7.

NIGBATI o si pari gbogbo ọ̀rọ rẹ̀ li etí
awọn enia, o wọ̀ Kapernaumu lọ.
2 Ọmọ-ọdọ balogun ọrún kan, ti o ṣọ-
wọn fun u, o ṣaisàn, o nkú lọ.
3 Nigbati o si gburó Jesu, o rán awọn
alàgba Ju si i, o mbẹ̀ ẹ pe, ki o máṣai wá
mu ọmọ-ọdọ on lara da.
4 Nigbati nwọn si de ọdọ Jesu, nwọn bẹ̀
ẹ lojukanna, wipe, O yẹ ẹniti on iba ṣe
eyi fun:
5 Nitoriti o fẹ awọn enia wa, o si ti kọ́
sinagogu kan fun wa.
6 Jesu si mba wọn lọ. Nigbati kò si
jìn si eti ile mọ́, balogun ọrún na rán awọn
ọrẹ́ si i, wipe, Oluwa má yọ ara rẹ lẹnu:
nitoriti emi kò yẹ ti iwọ iba fi wọ̀ abẹ orule
mi:
7 Bẹ̃li emi kò si rò pe emi na to lati tọ̀
ọ wá: ṣugbọn sọ ni gbolohùn kan, a o si
mu ọmọ-ọdọ mi lara da.
8 A sá si fi mi si abẹ oyè, mo li ọmọ-
ogun li ẹhin mi, mo wi fun ekini pe,
Lọ, a si lọ; ati fun ekeji pe, Wá, a si
wá; ati fun ọmọ-ọdọ mi pe, Ṣe eyi, a si
ṣe e.
9 Nigbati Jesu gbọ́ nkan wọnni, ẹnu
yà a si i, o si yipada si awọn enia ti ntọ̀ ọ
lẹhin, o wipe, Mo wi fun nyin, emi kò ri
irú igbagbọ́ nla bi eyi ninu awọn enia
Israeli.
10 Nigbati awọn onṣẹ pada rè ile, nwọn
ba ọmọ-ọdọ na ti nṣaisàn, ara rẹ̀ ti da.
11 ¶ O si ṣe ni ijọ keji, o rè ilu kan ti a
npè ni Naini; awọn pipọ ninu awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ si mba a lọ, ati ọ̀pọ enia.
12 Bi o si ti de ẹnu bode ilu na, si
kiyesi i, nwọn ngbé okú ẹnikan jade, ọmọ
kannaṣoṣo ti iya rẹ̀, o si jẹ opó: ọ̀pọ awọn
enia ilu na si wà pẹlu rẹ̀.
13 Nigbati Oluwa si ri i, ãnu rẹ̀ ṣe e, o
si wi fun u pe, Má sọkun mọ́.
14 O si wá, o si fi ọwọ́ tọ́ aga posi na:
awọn ti si nrù u duro jẹ. O si wipe,
Ọdọmọkọnrin, mo wi fun ọ, Dide.
15 Ẹniti o ku na si dide joko, o bẹ̀rẹ si
ohùn ifọ̀. O si fà a le iya rẹ̀ lọwọ.
16 Ẹ̀ru si ba gbogbo wọn: nwọn si nyìn
Ọlọrun logo, wipe, Woli nla dide ninu
wa; ati pe, Ọlọrun si wa ibẹ̀ awọn enia rẹ̀
wò.
17 Okikí rẹ̀ si kàn ni gbogbo Judea, ati
gbogbo àgbegbe ti o yiká.
18 Awọn ọmọ-ẹhin Johannu si fi ninu
gbogbo nkan wọnyi hàn fun u.
19 ¶ Nigbati Johannu si pè awọn meji
ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, o rán wọn sọdọ
Jesu, wipe, Iwọ li ẹniti mbọ̀, tabi ki a ma
reti ẹlomiran?
20 Nigbati awọn ọkọnrin na de ọdọ rẹ̀,
nwọn ni, Johannu Baptisti li o rán wá
sọdọ rẹ, wipe, Iwọ li ẹniti mbọ̀, tabi ki a
ma reti ẹlomiran?
21 Ni wakati na, o si ṣe dida ara pipọ
ninu arùn ati okunrun, ati awọn ẹmi bu-
buru wọn; o si fi iriran fun awọn afọju
pipọ.
22 Jesu si dahùn o wi fun wọn pe, Ẹ
pada lọ, ẹ ròhin nkan ti ẹnyin ri, ti ẹnyin
si gbọ́ fun Johannu; awọn afọju nriran,
awọn amọkun nrìn ṣaṣa, a sọ awọn adẹtẹ̀
di mimọ́, awọn aditi ngbọran, a njí awọn

Digitized by Google

okú dide, ati fun awọn òtoṣi li a nwasu
ihin-rere.
23 Alabukun-fun si li ẹnikẹni, ti kì yio
kọsẹ̀ lara mi.
24 ¶ Nigbati awọn onṣẹ Johannu pada
lọ, o bẹ̀rẹ si ibi awọn enia nipa Johannu
pe, Kili ẹnyin jade rè ijù lọ iwò? ifefe ti
afẹfẹ nmì?
25 Ani kili ẹnyin jade lọ iwò? Ọkọnrin
ti a wọ̀ li aṣọ fẹlẹfẹlẹ? wò o, awọn ti a wọ̀ li
aṣọ ogo, ti ara wọn tutù nini, mbẹ li afin
ọba.
26 Ani kili ẹnyin jade lọ iwò? woli?
lõtọ ni mo wi fun nyin, o si jù woli
lọ.
27 Eyiyi li ẹniti a ti kọwe nitori rẹ̀
pe, Wò o, mo rán onṣẹ mi siwaju rẹ, ẹniti
yio tún'ọ̀na rẹ ṣe niwaju rẹ.
28 Mo wi fun nyin, ninu awọn ti a bí
ninu obirin, kò si woli ti o pọ̀ju Johannu
Baptisti lọ: ṣugbọn ẹniti o kerejulọ ni
ijọba Ọlọrun, o pọ̀ju u lọ.
29 Gbogbo awọn enia ti o gbọ́ ati awọn
agbowode, nwọn da Ọlọrun lare, a baptisi
wọn ni baptismu Johannu.
30 Ṣugbọn awọn Farisi ati awọn amofin
ta ìmọ Ọlọrun nù kuro lọdọ ara wọn, a kò
baptisi wọn lọdọ rẹ̀.
31 ¶ Oluwa si wipe, Kili emi iba fi
awọn enia iran yi wé? kini nwọn si jọ?
32 Nwọn dabi awọn ọmọ kekere ti o joko
ni ibi ọjà, ti nwọn si nkọ si ara wọn, ti
nwọn si nwipe, Awa fun fère fun nyin,
ẹnyin kò jó; awa si ṣọ̀fọ fun nyin, ẹnyin
kò sọkun.
33 Nitori Johannu Baptisti wá, kò jẹ
akara, bẽni kò si mu ọti-waini; ẹnyin si
wipe, O li ẹmi èṣu.
34 Ọmọ-enia de, o njẹ o si nmu; ẹnyin
si wipe, Wò o, ọjẹun, ati ọmuti, ọrẹ́ awọn
agbowode ati awọn ẹlẹṣẹ!
35 Ṣugbọn a dare fun ọgbọ́n lati ọdọ
awọn ọmọ rẹ̀ gbogbo wá.
36 ¶ Farisi kan si rọ̀ ọ ki o wá ba on
jẹun. O si wọ̀ ile Farisi na lọ, o si joko
lati jẹun.
37 Si kiyesi i, obirin kan wà ni ilu na,
ẹniti iṣe ẹlẹṣẹ, nigbati o mọ̀ pe Jesu joko
njẹun ni ile Farisi, o mu ẽba alabastari
turari wá,
38 O si duro tì i lẹba ẹsẹ rẹ̀ lẹhin, o
nsọkun, o si bẹ̀rẹ si ifi omije wẹ̀ ẹ li ẹsẹ,
o si nfi irùn ori rẹ̀ nù u nù, o si nfi ẹnu kò
o li ẹsẹ, o si nfi turari kùn wọn.
39 Nigbati Farisi ti o pè e si ri i, o wi
ninu ara rẹ̀ pe, Ọkọnrin yi iba ṣe woli,
iba mọ̀ ẹni ati irú ẹniti obirin yi ṣe ti nfi
ọwọ́ bà a: nitori ẹlẹṣẹ ni.
40 Jesu si dahùn wi fun u pe, Simoni,
Mo ni ohun kan isọ fun ọ. O si dahùn
wipe, Olukọni, mã wi.
41 Onigbese kan wà ti o ni ajigbese
meji: ọkan jẹ ẹ ni ẹdẹgbẹta owo idẹ, ekeji
si jẹ ẹ ni adọta.
42 Nigbati nwọn kò si ni ti nwọn o san,
tinutinu li o darijì awọn mejeji. Wi,
ninu awọn mejeji tani yio fẹ ẹ jùlọ?
43 Simoni dahùn o si wipe, mo ṣebi
ẹniti o darijì jùlọ ni. O si wi fun u pe,
Iwọ fọ̀ rere.
44 O si yipada si obirin na, o wi fun
Simoni pe, Iwọ ri obirin yi? Emi wọ̀ ile
rẹ, omi wiwẹ̀ ẹsẹ iwọ kò fifun mi: ṣugbọn
on, omije li o fi nrọjo si mi li ẹsẹ, irun ori
rẹ̀ li o fi nnù wọn nù.
45 Ifẹnukonu iwo kò fi fun mi: ṣugbọn
obirin yi nigbati mo ti wọ̀ ile, ko dabọ̀ ẹnu
ifi kò mi li ẹsẹ.
46 Iwọ kò fi oróro pa mi li ori: ṣugbọn
obirin yi kò dakun turari ifi pa mi li ẹsẹ.
47 Njẹ mo wi fun ọ, A dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o
pọ̀ jì i; nitoriti o fẹràn pipọ: ẹniti a si
dari diẹ jì, on na li o fẹràn diẹ.
48 O si wi fun u pe, A dari ẹ̀ṣẹ rẹ jì ọ.
49 Awọn ti o bá a joko njẹun si bẹ̀rẹ si
irò ninu ara wọn pe, Tali eyi ti ndari ẹ̀ṣẹ
jì-ni pẹlu?
50 O si dahùn wi fun obirin na pe, Igba-
gbọ́ rẹ gbà ọ là; mã lọ si alafia.

## ORI 8.

O SI ṣe nikẹhin, ti o nlà gbogbo ilu ati
iletò lọ, o nwasu, o nrò ìhin ayọ̀ ijọba
Ọlọrun: awọn mejila si mbẹ lọdọ rẹ̀,
2 Ati awọn obirin kan, ti a ti mu lara
da kuro lọwọ awọn ẹmi buburu, ati ninu
ailera wọn, Maria ti a npè ni Magdalene,
lara ẹniti ẹmi èṣu meje ti jade kuro,
3 Ati Joanna aya Kusa ti iṣe iriju Hero-
du, ati Susanna, ati awọn miran pipọ, ti
nwọn nṣe iranṣẹ fun u ninu ohun ini wọn.
4 ¶ Nigbati ọ̀pọ awọn enia pejọ pọ̀, lati
ilu gbogbo tọ̀ ọ wá, o fi owe ba wọn sọrọ pe:
5 Afọnrugbin kan jade lọ lati fọn irugbin
rẹ̀: bi o si ti nfọnrugbin, diẹ bọ́ si ẹba ọ̀na;
a si tẹ̀ ẹ mọlẹ, awọn ẹiyẹ oju ọrun si ṣà
a jẹ.
6 Omiran si bọ́ sori apata; bi o si ti hù
jade, o gbẹ nitoriti kò ni irinlẹ omi.
7 Omiran si bọ́ sinu ẹgún; ẹgún si ba a
rú sokẽ, o si fun u pa.
8 Omiran si bọ́ si ilẹ rere, o si rú soke, o

Digitized by Google

si so eso ọrọrun. Nigbati o si wi nkan
wọnyi tan, o nahùn wipe, Ẹniti o ba li etí
lati fi gbọ́, ki o gbọ́.
9 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si bi i lẽre, wipe,
Kili a le mọ̀ owe yi si ?
10 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin li a fifun
lati mọ̀ ọ̀rọ ijinlẹ ijọba Ọlọrun: ṣugbọn
fun ẹlomiran li owe; ti nwọn nri ki nwọn
ki o má le ri, ti nwọn si ngbọ́ ki o má le yé
wọn.
11 Njẹ owe na li eyi: Irugbin li ọ̀rọ
Ọlọrun.
12 Awọn ti ẹba ọ̀na li awọn ti o gbọ́;
nigbana li Èṣu wá, o si mu ọ̀rọ na kuro li
ọkàn wọn, ki nwọn ki o má ba gbagbọ́, ki
a ma ṣe gbà wọn là.
13 Awọn ti ori apata li awọn, nigbati
nwọn gbọ́, nwọn fi ayọ̀ gbà ọ̀rọ na; nwọn
kò si ni gbòngbo, ti nwọn gbagbọ́ diẹ si,
nigbati o si di igba idanwò, nwọn a pada
sẹhin.
14 Awọn ti o bọ sinu ẹgún li awọn,
nigbati nwọn gbọ́ tan, nwọn lọ, nwọn a si
fi itọju ati ọrọ̀ ati irọra aiye fun u pa, nwọn
kò si le so eso asogbo.
15 Ṣugbọn ti ilẹ rere li awọn, ti nwọn fi
ọkàn otitọ ati rere gbọ ọ̀rọ na, nwọn pa a
mọ́, nwọn si fi sũru so eso.
16 ¶ Kò si ẹnikẹni, nigbati o ba tàn
fitilà tan, ti yio fi ohun ilò bò o mọlẹ, tabi
ti yio gbé e kà abẹ akete; bikoṣe ki o gbé
e kà ori ọpá fitilà, ki awọn ti nwọ̀ ile ki o
le ri imọlẹ.
17 Nitori kò si ohun ti o lumọ́, ti a kì
yio fi hàn, bẽni kò si ohun ti o pamọ́, ti a
kì yio mọ̀, ti kì yio si yọ si gbangba.
18 Njẹ ki ẹnyin ki o ma kiyesi ara bi
ẹnyin ti ngbọ́: nitori ẹnikẹni ti o ba ni, on
li a o fifun; ati ẹnikẹni ti kò ba si ni,
lọwọ rẹ̀ li a o si gbà eyi ti o ṣebi on ni.
19 ¶ Nigbana ni iya rẹ̀ on awọn arakọn-
rin rẹ̀ tọ̀ ọ wá, nwọn kò si le sunmọ ọ nito-
ri ifunpọ̀.
20 Nwọn si wi fun u pe, Iya rẹ ati awọn
arakọnrin rẹ duro lode, nwọn nfẹ ọ ri.
21 O si dahùn o si wi fun wọn pe, Iya
mi ati awọn arakọnrin mi li awọn wọnyi ti
nwọn ngbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun, ti nwọn si nṣe e.
22 ¶ O si ṣe ni ijọ kan, o si wọ̀ ọkọ̀ kan
lọ ti on ti awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀: o si wi fun
wọn pe, Ẹ jẹ ki awa ki o rekọja lọ si ìha
keji adagun. Nwọn si ṣikọ̀ lọ.
23 Bi nwọn si ti nlọ, o sùn; ẹfũfu nla
si de, o nfẹ li oju adagun; o si mu wọn
kún fun omi, nwọn si wà ninu ewu.
24 Nwọn si tọ̀ ọ wá, nwọn si jí i, wipe,
Olukọni, Olukọni, awa gbé. Nigbana li o
dide, o si ba ẹfufu on riru omi wi: nwọn si
da, idakẹ-rọrọ si de.
25 O si wi fun wọn pe, Igbagbọ́ nyin dà?
Bi ẹ̀ru ti mba gbogbo wọn, ti hà si nṣe wọn,
nwọn mbi ara wọn pe, Irú ọkọnrin kili eyi!
nitori o ba ẹfufu on riru omi wi, nwọn si
gbà a gbọ́.
26 ¶ Nwọn si gúnlẹ ni ilẹ awọn ara Ga-
dara, ti o kọju si Galili.
27 Nigbati o si sọkalẹ, ọkọnrin kan pade
rẹ̀ li ẹhin ilu na, ti o ti ni awọn ẹmi èṣu o
pẹ, ti kì iwọ̀ aṣọ, bẽni kì ijoko ni ile kan,
bikoṣe ni ile okú.
28 Nigbati o ri Jesu, o ke, o wolẹ niwa-
ju rẹ̀, o kigbe li ohùn rara, o ni, Kini emi
ni fi iwọ ṣe, Jesu, iwọ Ọmọ Ọlọrun Ọgá-
ogo? emi bẹ̀ ọ máṣe da mi loró.
29 (Nitoriti o ti wi fun ẹmi aimọ́ na pe,
ki o jade kuro lara ọkọnrin na. Nigba-
kugba ni nsá ma mu u: a si fi ẹ̀wọn ati
ṣẹkẹṣẹkẹ dè e; o si da gbogbo ìde na, ẹmi
èṣu na si dari rẹ̀ si ijù.)
30 Jesu si bi i pe, Orukọ rẹ? o si dahùn
pe, Legioni: nitoriti ẹmi èṣu pipọ wọ̀ ọ
lara lọ.
31 Nwọn si bẹ̀ ẹ pe, ki o máṣe rán wọn
lọ sinu ibu.
32 Agbo ẹlẹdẹ pipọ si mbẹ nibẹ̀ ti njẹ li
ori òke: nwọn si bẹ̀ ẹ ki o jẹ ki awọn wọ̀
inu wọn lọ. O si jọwọ wọn.
33 Nigbati awọn ẹmi èṣu si jade kuro
lara ọkọnrin na, nwọn si wọ̀ inu awọn ẹlẹdẹ
lọ: agbo ẹlẹdẹ si tupũ nwọn si sure lọ si
ibi bèbe sinu adagun, nwọn si rì ninu omi.
34 Nigbati awọn ti mbọ́ wọn ri ohun ti
o ṣe, nwọn sá, nwọn si lọ, nwọn si ròhin ni
ilu ati ni ilẹ na.
35 Nigbana ni nwọn jade lọ iwò ohun
na ti o ṣe; nwọn si tọ̀ Jesu wá, nwọn si ri
ọkọnrin na, lara ẹniti awọn ẹmi èṣu ti jade
lọ, o joko lẹba ẹsẹ Jesu, o wọṣọ, iyè rẹ̀ si bọ̀
si ipò: ẹ̀ru si ba wọn.
36 Awọn ti o ri i si ròhin fun wọn bi o
ti ṣe ti a fi mu ẹniti o li ẹmi èṣu lara da.
37 ¶ Nigbana ni gbogbo ijọ enia ti ilẹ
Gadara yiká bẹ̀ ẹ pe, ki o lọ kuro lọdọ wọn;
ẹ̀ru sá ba wọn gidigidi: o si bọ sinu ọkọ̀, o
pada sẹhin.
38 Njẹ ọkọnrin na ti ẹmi èṣu jade kuro
lara rẹ̀, o bẹ̀ ẹ ki on ki o le ma bá a gbé:
ṣugbọn Jesu rán a lọ, wipe,
39 Pada lọ ile rẹ, ki o si fi ohun ti Ọlọ-
run ṣe fun ọ hàn bi o ti pọ̀ to. O si lọ, o
si ròhin já gbogbo ilu na bi Jesu ti ṣe ohun
nla fun on to.

Digitized by Google

40 O si ṣe, nigbati Jesu pada lọ, awọn
enia tẹwọgbà a: nitoriti gbogbo nwọn ti
nreti rẹ̀.
41 ¶ Si kiyesi i, ọkọnrin kan ti a npè
ni Jairu, ọkan ninu awọn olori sinagogu, o
wá: o si wolẹ lẹba ẹsẹ Jesu, o bẹ̀ ẹ pe, ki o
máṣai wá si ile on:
42 Nitori o ni ọmọbirin kanṣoṣo, ọmọ
ìwọn ọdún mejila, o nkú lọ. Bi o si ti nlọ
awọn enia nhá a li àye.
43 ¶ Obirin kan ti o si li arùn ọ̀rin ẹ̀jẹ
lati igba ọdún mejila, ti o ná ohun gbogbo
ti o ni fun awọn oniṣegun, bẹ̃ni a kò le mu
u lara da lati ọwọ́ ẹnikan wá,
44 O wá lẹhin rẹ̀, o fi ọwọ́ tọ́ iṣẹti aṣọ rẹ̀:
lọgan ni isun ẹ̀jẹ rẹ̀ si ti gbẹ.
45 Jesu si wipe, Tali o fi ọwọ́ tọ́ mi?
Nigbati gbogbo wọn sẹ́, Peteru ati awọn ti
mbẹ lọdọ rẹ̀ wipe, Baba, awọn enia nhà ọ li
àye, nwọn si mbilù ọ, iwọ si wipe, Tali o fi
ọwọ́ tọ́ mi?
46 Jesu si wipe, Ẹnikan fi ọwọ́ tọ́ mi:
nitoriti emi mọ̀ pe aṣẹ jade lara mi.
47 Nigbati obirin na si mọ̀ pe on ko
pamọ́, on warìri o wá, o si wolẹ niwaju rẹ̀,
o si sọ fun u li oju awọn enia gbogbo nitori
ohun ti o ṣe, ti on fi fi ọwọ́ tọ́ ọ, ati bi ati
mu on lara da lojukanna.
48 O si wi fun u pe, Ọmọbirin, tújuka:
igbagbọ́ rẹ mu ọ lara da; mã lọ li alafia.
49 ¶ Bi o si ti nsọ̀rọ li ẹnu, ẹnikan ti ile
olori sinagogu wá, o wi fun u pe, Ọmọbirin
rẹ kú; má yọ olukọni lẹnu mọ.
50 Ṣugbọn nigbati Jesu gbọ́, o da a li
ohùn, wipe, Má bẹ̀ru: gbagbọ́ nikan ṣa, a
o si mu u lara da.
51 Nigbati Jesu si wọ̀ ile, kò jẹ ki ẹnikẹ-
ni wọle, bikoṣe Peteru, ati Jakọbu, ati
Johannu, ati baba on iya ọmọbirin na.
52 Gbogbo nwọn si sọkun, nwọn pohùn-
rere ẹkún rẹ̀: o si wi fun wọn pe, Ẹ
má sọkun mọ́; kò kú, sisùn li o sùn.
53 Nwọn si fi i ṣẹ̀fẹ, nwọn sa mọ̀ pe o
kú.
54 Nigbati o si sé gbogbo wọn mọ́ ode, o
mu u li ọwọ́, o si wipe, Ọmọbirin, dide.
55 Ẹmí rẹ̀ si tún pada wá, o si dide
lọgan: o ni ki nwọn ki o fun u li onjẹ.
56 Ẹnu si yà awọn õbi rẹ̀: ṣugbọn o
kilọ fun wọn pe, ki nwọn ki o máṣe wi
fun ẹnikan li ohun ti a ṣe.

## ORI 9.

NIGBANA li o si pè awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
mejila jọ, o si fun wọn li agbara on
ọlá lori awọn ẹmi ẽṣu gbogbo, ati lati wò
arùn sàn.
2 O si rán wọn lọ iwasu ijọba Ọlọrun,
ati lati mu awọn olokunrun lara da.
3 O si wi fun wọn pe, Ẹ máṣe mu nkan
lọ fun àjo nyin, ọpá ipo, tabi birigami,
tabi akara, tabi owo; bẹ̃ni ki ẹnyin ki o
má si ṣe li ẹ̀wu meji.
4 Ni ilekile ti ẹnyin ba wọ̀ si, nibẹ̀ ni ki
ẹnyin ki o duro, lati ibẹ̀ ni ki ẹnyin ki o
si ti jade lọ.
5 Ẹnikẹni ti kò ba fẹ lati gbà nyin, ni-
gbati ẹnyin ba jade kuro ni ilu na, ẹ gbọ̀n
ekuru iyekuru ẹsẹ nyin ṣe ẹrí si wọn.
6 Nwọn si jade, nwọn nlà iletò lọ, nwọn
si nwasu ihin-rere, nwọn si nmu enia lara
da nibi gbogbo.
7 ¶ Herodu tetrarki si gbọ́ nkan gbogbo
ti nṣe lati ọdọ rẹ̀ wá: o si damu, nitori ti
a nwi lọdọ ẹlomiran pe, Johannu li o tún
jinde kuro ninu okú;
8 Ati lọdọ ẹlomiran pe, Elijah li o fi ara
hàn; ati lọdọ ẹlomiran pe, ọkan ninu awọn
woli atijọ li o tún jinde.
9 Herodu si wipe, Johannu ni mo ti bẹ́
lori: ṣugbọn tali eyi, ti emi ngbọ́ irú nkan
wọnyi nitori rẹ̀? O si nfẹ lati ri i.
10 ¶ Nigbati awọn aposteli si pada de,
nwọn ròhin ohun gbogbo fun u ti nwọn ti
ṣe. O si mu wọn, o si lọ si apakan nibi
ijù ti iṣe ti ilu ti a npè ni Betsaida.
11 Nigbati awọn enia si mọ̀, nwọn tọ̀ ọ
lọ: o si gbà wọn, o si sọ̀rọ ijọba Ọlọrun
fun wọn, awọn ti o fẹ imularada, li o si
mu lara da.
12 Nigbati ọjọ bẹ̀rẹ si irẹlẹ, awọn mejila
wá, nwọn si wi fun u pe, Tú ijọ enia ká, ki
nwọn ki o le lọ si iletò ati si ilu yiká, ki
nwọn ki o le wọ̀, ati ki nwọn ki o le wá
onjẹ jẹ: nibi ijù li awa sá gbé wà nihinyi.
13 Ṣugbọn o wi fun wọn pe, Ẹ fi onjẹ
fun wọn jẹ. Nwọn si wi fun u pe, Awa kò
ni jù iṣu akara marun lọ, pẹlu ẹja meji;
bikoṣepe awa lọ irà onjẹ fun gbogbo awọn
enia wọnyi.
14 Nitori awọn ọkọnrin to ìwọn ẹgbẹdo-
gbọn enia. O si wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
pe, ki nwọn ki o mu wọn joko li ẹgbẹ-ẹgbẹ,
li aradọta.
15 Nwọn si ṣe bẹ̃, nwọn si mu gbogbo
wọn joko.
16 Nigbana li o mu iṣu akara marun,
ati ẹja meji na, nigbati o gbé oju soke, o
sure si i, o si bù u, o si fifun awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o gbé e kalẹ niwaju
awọn enia.

Digitized by Google

17 Nwọn si jẹ, gbogbo wọn si yó: nwọn
ṣà agbọ̀n mejila jọ ninu ajẹkù ti o kù fun
wọn.
18 ¶ O si ṣe, nigbati o kù on nikan, o
ngbadura, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si wà lọdọ rẹ̀:
o si bi wọn pe, Tali awọn enia nfi emi pè?
19 Nwọn si dahùn wipe, Johannu Bap-
tisti; ṣugbọn ẹlomiran ni, Elijah ni; ati
awọn ẹlomiran wipe, ọkan ninu awọn woli
atijọ li o jinde.
20 O si bi wọn pe, Ṣugbọn tali ẹnyin nfi
emi ipè? Peteru si dahùn, wipe, Kristi ti
Ọlọrun.
21 O si kìlọ fun wọn gidigidi pe, ki
nwọn ki o máṣe sọ ohun na fun ẹnikan.
22 O si wipe, Ọmọ-enia kò le ṣaima jìya
ohun pipọ, a o si kọ̀ ọ lati ọdọ awọn alàgba,
ati lati ọdọ awọn olori alufa, ati lati ọdọ
awọn akọwe wá, a o si pa a, ni ijọ kẹta a o
si gbé e dide.
23 ¶ O si wi fun gbogbo wọn pe, Bi
ẹnikan ba nfẹ lati mã tọ̀ mi lẹhin, ki o sẹ́
ara rẹ̀, ki o si gbé agbelebu rẹ ni ijọ gbo-
gbo, ki o si mã tọ̀ mi lẹhin.
24 Nitori ẹnikẹni ti o ba gbà ẹmí rẹ̀ là,
yio sọ ọ nù: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba sọ ẹmí
rẹ̀ nù nitori mi, on na ni yio si gbà a là.
25 Nitoripe ère kini fun enia, bi o jère
gbogbo aiye, ti o si sọ ara rẹ̀ nù, tabi ki o fi
ara rẹ̀ ṣòfò.
26 Nitori ẹnikẹni ti o ba tiju mi, ati
ọ̀rọ mi, oju rẹ̀ li Ọmọ-enia yio si tì, nigbati
o ba de inu ogo tirẹ̀, ati ti baba rẹ̀, ati ti
awọn angeli mimọ́.
27 Ṣugbọn emi wi fun nyin nitõtọ, ẹlo-
miran duro nihinyi, ti kì yio ri ikú, titi
nwọn o fi ri ijọba Ọlọrun.
28 ¶ O si ṣe bi iwọn ijọ kẹjọ lẹhin ọ̀rọ
wọnyi, o mu Peteru, ati Johannu, ati
Jakọbu, o gùn ori òke lọ lati gbadura.
29 Bi o si ti ngbadura, àwọ oju rẹ̀ yipa-
da, aṣọ rẹ̀ si fun lawu o njo fòfo.
30 Si kiyesi i, awọn ọkọnrin meji, ti iṣe
Mose on Elijah nwọn mba a sọ̀rọ:
31 Ti nwọn fi ara hàn li ogo, nwọn si
nsọ ọ̀rọ ikú rẹ̀, ti on o pari ni Jerusalemu.
32 Ṣugbọn oju Peteru ati ti awọn ti mbẹ
lọdọ rẹ̀ wuwo fun orun: nigbati nwọn si
tají, nwọn ri ogo rẹ̀, ati ti awọn ọkọnrin
mejeji ti o ba a duro.
33 O si ṣe, nigbati nwọn lọ kuro lọdọ rẹ̀,
Peteru wi fun Jesu pe, Baba, o dara fun
wa ki a ma gbé ihinyi: jẹ ki awa ki o pa
agọ́ mẹta; ọkan fun iwọ, ati ọkan fun
Mose, ati ọkan fun Elijah: kò mọ̀ eyi ti o
nwi.
34 Bi o ti nsọ bayi, ikũkũ kan wá, o ṣiji
bò wọn: ẹ̀ru si ba wọn nigbati nwọn nwọ̀
inu ikuku lọ.
35 Ohùn kan si ti inu ikũkũ wá, o ni,
Eyiyi li ayanfẹ Ọmọ mi: ẹ ma gbọ́ tirẹ̀.
36 Nigbati ohùn na si dakẹ, Jesu nikan-
ṣoṣo li a ri. Nwọn si pa a mọ́, nwọn kò
si sọ ohunkohun ti nwọn ri fun ẹnikẹni ni
ijọ wọnni.
37 ¶ O si ṣe, ni ijọ keji, nigbati nwọn
sọkalẹ lati ori òke wá, ọ̀pọ awọn enia wá
ipade rẹ̀.
38 Si kiyesi i, ọkọnrin kan ninu ijọ ki-
gbe soke, wipe, Olukọni, mo bẹ̀ ọ, wò ọmọ
mi; nitori ọmọ mi kanṣoṣo na ni.
39 Si kiyesi i, ẹmi èṣu a ma mu u, a si
ma kigbe lojijì; a si ma nà a tàntàn titi
yio fi yọ ifófó li ẹnu, a ma pa a lara, a tilẹ
fẹrẹ má fi i silẹ lọ.
40 Mo si bẹ̀ awọn ọmọ-ẹhin rẹ lati lé e
jade; nwọn kò si le ṣe e.
41 Jesu si dahùn, wipe, Iran alaigbagbọ́
ati arekereke, emi o ti ba nyin gbé pẹ to?
emi o si ti ṣe sũru fun nyin pẹ to? Fà ọmọ
rẹ wá nihinyi.
42 Bi o si ti mbọ̀, ẹmi èṣu na gbé e
ṣanlẹ, o si nà a tantan. Jesu si ba ẹmi
aimọ́ na wi, o si mu ọmọ na lara da, o si fà
a le baba rẹ̀ lọwọ.
43 ¶ Ẹnu si yà gbogbo wọn si iṣẹ ọlá
Ọlọrun. Ṣugbọn nigbati hà si nṣe gbogbo
wọn si ohun gbogbo ti Jesu ṣe, o wi fun
awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe,
44 Ẹ jẹ ki ọrọ wọnyi ki o rì si nyin li
etí: nitori a o fi Ọmọ-enia le awọn enia
lọwọ.
45 Ṣugbọn ọ̀rọ na kò yé wọn, o si ṣú
wọn li oju, bẽni nwọn kò si mọ̀ ọ: ẹ̀ru si
mba wọn lati bère idi ọ̀rọ na.
46 ¶ Nigbana ni ìro kan wà ninu wọn
pe, tani ninu wọn ti yio ṣe olori.
47 Nigbati Jesu si mọ̀ ìro ọkàn wọn o
mu ọmọde kan, o gbé e joko lọdọ rẹ̀,
48 O si wi fun wọn pe, Ẹnikẹni ti o ba
gbà ọmọde yi nitori orukọ mi, o gbà mi:
ati ẹnikẹni ti o ba gbà mi, o gbà ẹniti o
rán mi: nitori ẹniti o ba kereju ninu gbo-
gbo nyin, on na ni yio pọ̀.
49 ¶ Johannu si dahùn o si wi fun u pe,
Baba, awa ri ẹnikan o nfi orukọ rẹ lé awọn
ẹmi èṣu jade; awa si da a lẹkun nitoriti kò
ba wa tọ̀ ọ lẹhin.
50 Jesu si wi fun u pe, Màṣe da a lẹkun
mọ́: nitori ẹniti kò ba lodi si wa, on ni ti
wa.
51 ¶ O si ṣe, nigbati ọjọ atigbà soke rẹ̀

Digitized by Google

pé, o gbé oju le gangan lati lọ si Jerusa-
lemu.
52 O si rán awọn onṣẹ lọ si iwaju rẹ̀:
nigbati nwọn si lọ, nwọn wọ̀ iletò kan ti
iṣe ti ara Samaria lọ ipèse silẹ dè e.
53 Nwọn kò si gbà a, nitoriti oju rẹ̀
dabi ẹnipe o nlọ si Jerusalemu.
54 Nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ Jakọbu on
Johannu si ri i, nwọn ni, Oluwa, iwọ ko jẹ
ki awa ki o pè iná lati ọrun wá, ki a sun
wọn lúlu, bi Elijah ti ṣe?
55 Ṣugbọn Jesu yipada, o si ba wọn wi,
o ni, Ẹnyin kò mọ̀ irú ẹmí ti mbẹ ninu
nyin.
56 Nitori Ọmọ-enia ko wá lati pa ẹmi
enia run, bikoṣe lati gbà a là. Nwọn si lọ
si iletò miran.
57 ¶ O si ṣe, bi nwọn ti nlọ li ọ̀na ọkọn-
rin kan wi fun u pe, Oluwa, Emi nfẹ lati
ma tọ̀ ọ lẹhin nibikibi ti iwọ ba nlọ.
58 Jesu si wi fun u pe, Awọn kọ̀lọkọlọ
ni ihò, awọn ẹiyẹ oju ọrun si ni itẹ́; ṣugbọn
Ọmọ-enia, kò ni ibi ti yio fi ori rẹ̀ le.
59 O si wi fun ẹlomiran pe, Mã tọ̀ mi
lẹhin. Ṣugbọn o wi fun u pe, Oluwa, jẹ
ki emi ki o tète lọ isinku baba mi na.
60 Jesu si wi fun u pe, Jẹ ki awọn okú
ki o ma sinkú ara wọn: ṣugbọn iwọ lọ ki
o si ma wãsu ijọba Ọlọrun.
61 Ẹlomiran si wi fun u pe, Oluwa, emi
nfẹ lati mã tọ̀ ọ lẹhin; ṣugbọn jẹ ki emi
ki o pada lọ idagbere fun awọn ará ile mi.
62 Jesu si wi fun u pe, Kò si ẹni, ti o fi
ọwọ́ rẹ̀ le ohunelo itulẹ, ti o si wò ẹhin, ti
o yẹ fun ijọba Ọlọrun.

## ORI 10.

LẸHIN nkan wọnyi, Oluwa si yàn adọrin
ọmọ-ẹhin miran pẹlu, o si rán wọn ni
mejimeji lọ ṣiwaju rẹ̀, si gbogbo ilu ati ibi,
ti on tikararẹ̀ yio gbé de.
2 O si wi fun wọn pe, Ikore pọ̀, ṣugbọn
awọn alagbaṣe ko to nkan: ki ẹnyin ki o
bẹ̀ Oluwa ikore, ki o le rán awọn alagbaṣe
sinu ikore rẹ̀.
3 Ẹ mu ọ̀na nyin pọn: sawò o, emi rán
nyin lọ bi ọdọ-agutan sãrin ikõkò.
4 Ẹ máṣe mu asuwọn ẹ máṣe mu biri-
gami, tabi bàta; ki ẹnyin ki o máṣe kí
ẹnikẹni li ọ̀na.
5 Ni ilekile ti ẹnyin ba wọ̀, ki ẹnyin ki
o tète wipe, Alafia fun ile yi.
6 Bi ọmọ alafia ba mbẹ nibẹ̀, alafia nyin
yio bà le e: bi kò ba si, yio si tún pada si
nyin.
7 Ni ile na ni ki ẹnyin ki o gbé, ki
ẹnyin ki o ma jẹ, ki ẹnyin ki o si ma mu
ohunkohun ti nwọn fifun nyin; nitori ọ̀ya
alagbaṣe tọ́ si i. Ki ẹnyin ki o máṣe ati
ile ṣí si ile.
8 Ati ni ilukilu ti ẹnyin ba wọ̀, ti nwọn
ba si gbà nyin, ki ẹnyin ki o jẹ ohunkohun
ti a gbé kalẹ niwaju nyin:
9 Ki ẹnyin ki o si mu awọn olokunrun
ti mbẹ ninu rẹ̀ lara da, ki ẹnyin ki o si wi
fun wọn pe, Ijọba Ọlọrun kù si nyin dẹ̀dẹ.
10 Ṣugbọn ni ilukilu ti ẹnyin ba si wọ̀,
ti nwọn kò ba si gbà nyin, nigbati ẹnyin
ba si jade si igboro ilu na, ki ẹnyin ki o si
wipe,
11 Ekuru iyekuru ilu nyin ti o kù mọ́
wa lara, awa si nù u nù si nyin: ṣugbọn
ki eyi ki o yé nyin pe, ijọba Ọlọrun kù si
nyin dẹ̀dẹ.
12 Ṣugbọn emi wi fun nyin, yio san fun
Sodomu ni ijọ na, jù fun ilu na lọ.
13 Egbé ni fun iwọ, Korasini! Egbé ni
fun iwọ Betsaida! ibaṣepe a ti ṣe iṣẹ agbara
ti a ṣe ninu nyin, ni Tire on Sidoni, awọn
iba ti ronupiwada lailai li aṣọ ọ̀fọ ati ninu
ẽru.
14 Ṣugbọn yio san fun Tire on Sidoni
nigba idajọ, jù fun ẹnyin lọ.
15 Ati iwọ, Kapernaumu, ti a gbéga
soke ọrun, iwọ li a o si sọkalẹ si ọrun
apadi.
16 Ẹniti o ba gbọ́ ti nyin, o gbọ́ ti emi:
ẹniti o ba si gàn nyin, o gàn mi; ẹniti o
ba si gàn mi, o gàn ẹniti o rán mi.
17 ¶ Awọn adọrin na si tún pada ti
awọn ti ayọ̀, wipe, Oluwa, ani awọn ẹmi
èṣu foribalẹ fun wa nitori orukọ rẹ.
18 O si wi fun wọn pe, Emi ri Satani bi
mànamána o ṣubu ti ọrun wá.
19 Kiyesi i, emi fun nyin li agbara lati
tẹ̀ ejò ati akẽkẽ mọlẹ, ati lori gbogbo
agbara ọtá: kò si ohun kan bi o ti wù ki o
ṣe, ti yio pa nyin lara.
20 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o máṣe yọ̀ si eyi,
nitoriti awọn ẹmi nforibalẹ fun nyin;
ṣugbọn ki ẹnyin ki o kuku yọ̀, nitoriti a
kọwe orukọ nyin li ọrun.
21 ¶ Ni wakati na ni Jesu yọ̀ li ọkàn, o
si wipe, Mo dupẹ lọwọ rẹ, Baba, Oluwa
ọrun on aiye, nitoriti iwọ pa nkan wọnyi
mọ́ kuro lọdọ awọn ọlọ́gbọn ati amoye, iwọ
si fi wọn hàn fun awọn ọmọ ọwọ: bẹ̃ni,
Baba, bẹ̃li o sá yẹ li oju rẹ.
22 Ohun gbogbo li a fifun mi lati ọdọ
Baba mi wá: kò si si ẹni ti o mọ̀ ẹniti
Ọmọ iṣe, bikoṣe Baba; ati ẹniti Baba iṣe,

Digitized by Google

bikoṣe Ọmọ, ati ẹniti o si wù Ọmọ a fi i
hàn fun.
23 ¶ O si yipada si awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ li
apakan, o ni, Ibukún ni fun oju ti nri ohun
ti ẹnyin nri:
24 Nitori mo wi fun nyin, Woli ati ọba
pipọ li o nfẹ lati ri ohun ti ẹnyin nri, nwọn
kò si ri wọn; ati lati gbọ́ ohun ti ẹnyin
ngbọ́, nwọn kò si gbọ́ wọn.
25 ¶ Si kiyesi i, amofin kan dide, o ndán
a wò, o ni, Olukọni, kili emi o ṣe ki emi ki
o le jogún iye ainipẹkun?
26 O si bi i pe, Kili a kọ sinu iwe ofin?
bi iwọ ti kà a?
27 O si dahùn wipe, Ki iwọ ki o fi gbo-
gbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo
agbara rẹ, ati gbogbo inu rẹ fẹ Oluwa Ọlọ-
run rẹ; ati ẹnikeji rẹ bi ara rẹ.
28 O si wi fun u pe, Iwọ dahùn rere: ṣe
eyiyi, iwọ o si yè.
29 Ṣugbọn o nfẹ lati yìn ara rẹ̀, o wi fun
Jesu pe, Tani ha li ẹnikeji mi?
30 Jesu si dahùn o wipe, Ọkọnrin kan
nti Jerusalemu sọkalẹ lọ si Jeriko, o si bọ
si ọwọ́ awọn olè, ti nwọn gbà a li aṣọ, nwọn
ṣá a lọgbẹ, nwọn si fi i silẹ lọ li aipa li
apatan.
31 Ni alabapade li alufa kan nsọkalẹ lọ
niha ibẹ̀: nigbati o si ri i, o kọja lọ niha
keji.
32 Ati Lefite kan pẹlu, nigbati o de ibẹ̀,
o wá, o wò o, o si kọja lọ niha keji.
33 Ṣugbọn ara Samaria kan, bi o ti nrè
àjo, o de ibi ti o gbé wà: nigbati o si ri i,
ãnu ṣe e,
34 O si tọ̀ ọ lọ, o si dì i lọgbẹ, o da oróro
on ọti-waini si i, o si gbé e le ori ẹranko rẹ̀
ti o ngùn, o si mu u wá si ile èro, o si nṣe
itọju rẹ̀.
35 Nigbati o si lọ ni ijọ keji, o fi owo idẹ
meji fun bãle èro, o si wi fun u pe, Mã
tọju rẹ̀; ohunkohun ti iwọ ba si ná si i,
nigbati mo ba pada de, emi o san a fun ọ.
36 Ninu awọn mẹtẹta wọnyi, tani iwọ
ṣebi iṣe ẹnikeji ẹniti o bọ si ọwọ́ awọn olè?
37 O si dahùn wipe, Ẹniti o ṣãnu fun u.
Jesu si wi fun u pe, Lọ, ki iwọ ki o si ṣe
bẽ gẹgẹ.
38 ¶ O si ṣe, bi nwọn ti nlọ, o wọ̀ iletò
kàn: obirin kan ti a npè ni Marta si gbà
a si ile rẹ̀.
39 O si ni arabirin kan ti a npè ni Maria,
ti o si joko lẹba ẹsẹ̀ Jesu, ti o ngbọ́ ọ̀rọ
rẹ̀.
40 Ṣugbọn Marta nṣe iyọnu ohun pipọ,
o si tọ̀ ọ wá, o ni, Oluwa, iwọ kò kuku ṣu
si i ti arabirin mi fi mi silẹ lati ma nikan ṣe
aisimi? Wi fun u ki o ràn mi lọwọ.
41 Jesu si dahùn, o si wi fun u pe,
Marta, Marta, iwọ nṣe aniyan ati lãlã nitori
ohun pipọ:
42 Ṣugbọn ohun kan li a kò le ṣe alaini.
Maria si ti yàn ipa-ọ̀na rere na, ti a kò le
gbà lọwọ rẹ̀.

## ORI 11.

O SI ṣe, bi o ti ngbadura ni ibi kan, bi o
ti dakẹ, ọkan ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
wi fun u pe, Ọluwa, kọ́ wa bi ãti igbadura,
bi Johannu si ti kọ́ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀.
2 O si wi fun wọn pe, Nigbati ẹnyin ba
ngbadura, ẹ ma wipe, Baba wa ti mbẹ li
ọrun, Jẹ ki a bọ̀wọ̀ fun orukọ rẹ. Ki ijọba
rẹ de. Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, bi ti ọrun, bẹni
li aiye.
3 Fun wa li onjẹ ojọ wa li ojojumọ́.
4 Ki o si dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa; nitoriti awa
a si ma dari ẹ̀ṣẹ jì olukuluku ẹniti o jẹ wa
ni gbese. Má si fà wa sinu idẹwò; ṣugbọn
gbà wa ninu tulasi.
5 O si wi fun wọn pe, Tani ninu nyin ti
yio ni ọrẹ́ kan, ti yio si tọ̀ ọ lọ larin ọganjọ,
ti yio si wi fun u pe, Ọrẹ́, win mi ni iṣu
akara mẹta:
6 Nitoriti ọrẹ́ mi kan ti àjo bọ sọdọ mi,
emi kò si ni nkan ti emi o gbé kalẹ niwaju
rẹ̀?
7 Ti on o si gbé inu ile dahùn wi fun u
pe, Má yọ mi lẹnu: a ti sé ilẹkun na, awọn
ọmọ mi si mbẹ lori ẹní pẹlu mi; emi kò le
dide fifun ọ.
8 Emi wi fun nyin, bi on kò tilẹ fẹ dide
ki o fifun u, nitoriti iṣe ọrẹ́ rẹ̀, ṣugbọn ni-
tori awiyannu rẹ̀ yio dide, yio si fun u pọ̀
to bi o ti nfẹ.
9 Mo si wi fun nyin, Ki ẹnyin ki o bère,
a o si fifun nyin; ẹ wá kiri, ẹnyin o si ri;
ẹ kànkun, a o si ṣi i silẹ fun nyin.
10 Nitori ẹnikẹni ti o bère o ri gbà;
ẹniti o si nwá kiri o ri; ati ẹniti o kànkun
li a o ṣí i silẹ fun.
11 Tani iṣe baba ninu nyin ti ọmọ rẹ̀ yio
bère akara lọdọ rẹ̀, ti o jẹ fun u li okuta?
tabi bi o bère ẹja, ti o jẹ fun u li ejò?
12 Tabi bi o si bère ẹyin, ti o jẹ fun u li
akẽkẽ?
13 Njẹ bi ẹnyin ti iṣẹ enia buburu ba
mọ̀ bi ati ifi ẹ̀bun didara fun awọn ọmọ
nyin: melomelo ni Baba nyin ti mbẹ li
ọrun yio fi Ẹmí Mimọ́ rẹ̀ fun awọn ti o
mbère lọdọ rẹ̀?
14 ¶ O si nlé ẹmi èṣu kan jade, ti o si

Digitized by Google

yadi. O si ṣe, nigbati ẹmi èṣu na jade,
odi nfọhun; ẹnu si yà awọn enia.
15 Ṣugbọn awọn ẹlomiran ninu wọn
wipe, Ọlá Beelsebubu olori awọn ẹmi èṣu li
o fi nle awọn èṣu jade.
16 Ati awọn ẹlomiran, ndán a wò, nwọn
nfẹ ki o fi àmi kan hàn fun wọn lati ọrun
wá.
17 Ṣugbọn on mọ̀ ìro inu wọn, o wi fun
wọn pe, Gbogbo ijọba ti o yà ara rẹ̀ ni ipa,
a sọ ọ di ahoro; ile ti o si yà ara rẹ̀ ni ipa,
a wó.
18 Bi Satani si yàpa si ara rẹ̀, ijọba rẹ̀
yio ha ṣe duro? nitoriti ẹnyin wipe emi nfi
ọlá Beelsebubu lé awọn ẹmi èṣu jade.
19 Bi o ba si ṣepe ọlá Beelsebubu li emi
fi nlé awọn ẹmi èṣu jade, ọlá tali awọn ọmọ
nyin fi nlé wọn jade? nitorina ni nwọn o fi
ma ṣe onidajọ nyin.
20 Ṣugbọn bi o ba ṣepe ika Ọlọrun li
emi fi nlé awọn ẹmi èṣu jade, kò si aniani,
ijọba Ọlọrun de ba nyin.
21 Nigbati ọkọnrin alagbara ti o hamọra
ba nṣọ afin rẹ̀, ẹrù rẹ̀ a wà li alafia:
22 Ṣugbọn nigbati ọkọnrin alagbara jù u
ba kọlù u, ti o ṣẹgun rẹ̀, o gbà gbogbo
ihamọra rẹ̀ ti o gbẹkẹle lọwọ rẹ̀, a si pín
gbogbo ikogun rẹ̀.
23 Ẹniti kò ba bá mi gbé, o nṣe òdi si
mi: ẹniti kò ba si bá mi kopọ̀, o nfọn ká
kiri.
24 Nigbati ẹmi aimọ́ ba jade kuro lara
enia, ama rìn kiri ni ibi gbigbẹ, ama wá ibi
isimi; nigbati ko si ri, o ni, Emi o pada lọ
si ile mi nibiti mo gbé ti jade lọ.
25 Nigbati o si de, o bá a, a gbá a, a si
ṣe e li ọṣọ́.
26 Nigbana li o lọ, o si mu ẹmi meje
miran ti o buru jù on tikararẹ̀ lọ; nwọn
wọle, nwọn si joko nibẹ̀: asiwa ọkọnrin na
si buru jù ti iṣaju rẹ̀ lọ.
27 ¶ O si ṣe, bi o ti nsọ nkan wọnyi,
obirin kan nahùn ninu ijọ, o si wi fun u
pe, Ibukun ni fun inu ti o bí ọ, ati ọmú ti
iwọ mu.
28 Ṣugbọn o wipe, Nitõtọ, ki a kuku
wipe, Ibukun ni fun awọn ti ngbọ́ ọ̀rọ Ọlọ-
run, ti nwọn si pa a mọ́.
29 ¶ Nigbati awọn enia si ṣù jọ si ibi
kan, o bẹ̀rẹ si iwipe, Iran buburu li eyi:
nwọn nwá àmi; a kì yio si fi àmi kan fun
u, bikoṣe àmi Jona woli.
30 Nitori bi Jona ti ṣe àmi fun awọn ara
Ninefe, gẹgẹ bẹ̃ li Ọmọ-enia yio ṣe àmi fun
iran yi.
31 Ayaba gusù yio dide li ọjọ idajọ si
awọn enia iran yi, yio si da wọn lẹbi: ni-
toriti o ti iha ipẹkun aiye wá lati gbọ́
ọgbọ́n Solomoni; si kiyesi i, ẹniti o pọ̀ju
Solomoni lọ mbẹ nihinyi.
32 Awọn ara Ninefe yio dide li ọjọ idajọ
si iran yi, nwọn o si da a lẹbi: nitoriti
nwọn ronupiwada nipa iwasu Jona; si kiye
si, ẹniti o pọ̀ju Jona lọ mbẹ nihinyi.
33 Kò si ẹnikẹni, nigbati o ba tàn fitila
tan, ti igbé e si ìkọkọ, tabi sabẹ oṣuwọn,
bikoṣe lori ọpá fitilà, ki ẹnikẹni ti o wọle
ki o le ma ri imọlẹ.
34 Oju ni imọlẹ ara: bi oju rẹ ba mọ́,
gbogbo ara rẹ a si mọlẹ; ṣugbọn bi oju rẹ
ba buru, ara rẹ gbogbo a si ṣú fun òkunkun.
35 Ki ẹnyin ki o ma kiyesi i, ki imọlẹ ti
mbẹ lara nyin ki o máṣe di òkunkun.
36 Njẹ bi gbogbo ara rẹ ba jẹ imọlẹ, ti
kò li apakan ti o ṣú, ara rẹ gbogbo ni yio
si mọ́, bi igba ti itànṣan fitila fun ọ ni
imọlẹ.
37 ¶ Bi o si ti nwi, Farisi kan bẹ̀ ẹ ki o
ba on jẹun: o si wọle, o joko lati jẹun.
38 Nigbati Farisi na si ri i, ẹnu yà a
nitoriti kò tète wẹ̀ ki o to joko ti onjẹ.
39 Oluwa si wi fun u pe, Ẹnyin Farisi a
ma fọ ẹhin ago ati awopọkọ́; ṣugbọn inu
nyin kún fun iwọra ati fun ìka.
40 Ẹnyin aṣiwere, ẹniti o ṣe eyi ti mbẹ
lode, on ki o ṣe eyi ti mbẹ ninu pẹlu?
41 Ki ẹnyin ki o kuku ma ṣe itọrẹ ãnu
ninu ohunkohun ti ẹnyin ni; si kiyesi i,
ohun gbogbo li o di mimọ́ fun nyin.
42 Ṣugbọn egbé ni fun nyin, ẹnyin
Farisi! nitoriti ẹnyin a ma san idamẹwa
minti, ati rue, ati gbogbo ewekewe, ṣugbọn
ẹnyin mu oju kuro ninu idajọ ati ifẹ Ọlọ-
run: wọnyi li ẹnyin iba ṣe, ẹnyin ki ba si
ti fi ekeji silẹ laiṣe.
43 Egbé ni fun nyin, ẹnyin Farisi! ni-
toriti ẹnyin a ma fẹ ipò ọlá ninu sinagogu,
ati ikí-ni li ọjà.
44 Egbé ni fun nyin ẹnyin akọwe, ati
ẹnyin Farisi, agabagebe! nitoriti ẹnyin
dabi ilẹpa-okú ti kò hàn, awọn ẹniti si nrìn
lori wọn kò mọ̀.
45 ¶ Nigbana li ọkan ninu awọn amofin
dahùn, o si wi fun u pe, Olukọni, li eyi ti
iwọ nwi nì iwọ ngàn wa pẹlu.
46 O si wipe, Egbé ni fun ẹnyin amofin
pẹlu! nitoriti ẹnyin di ẹrù ti o wuwo lati
rù le ejika enia, bẽni ẹnyin tikara nyin kò
jẹ fi ika nyin kan kàn ẹrù na.
47 Egbé ni fun nyin! nitoriti ẹnyin kọ́le
oju-õri awọn woli, awọn baba nyin li o si ti
pa wọn.

Digitized by Google

48 Lõtọ li ẹnyin jẹri pe, ẹnyin li ọwọ́
ninu iṣe awọn baba nyin: nitori nwọn pa
wọn nitõtọ, ẹnyin si kọ́le oju-õrì wọn.
49 Nitori eyi na li ọgbọ́n Ọlọrun si ṣe
wipe, emi o rán awọn woli ati awọn apos-
teli si wọn, ninu wọn ni nwọn o pa, ti
nwọn o si ṣe inunibini si:
50 Ki a le bère ẹ̀jẹ awọn woli gbogbo, ti
a ti ta silẹ lati igba ipilẹṣẹ aiye wá, lọdọ
iran yi;
51 Lati ẹ̀jẹ Abeli wá, titi o si fi de ẹ̀jẹ
Sakariah, ti o ṣegbé lãrin pẹpẹ on tempili:
lõtọ ni mo wi fun nyin, A o bère rẹ̀ lọdọ
iran yi.
52 Egbé ni fun nyin, ẹnyin amofin!
nitoriti ẹnyin gbà ọmọ-ṣika ìmọ: ẹnyin
tikara nyin kò wọle, awọn ti si nwọle, ẹnyin
kọ̀ fun won.
53 Bi o si ti nwi nkan wọnyi fun wọn,
awọn akọwe ati awọn Farisi bẹ̀rẹ si iyọ ọ
lohùn gidigidi, nwọn si ntọ́ ọ lati wi nkan
pipọ:
54 Nwọn nṣọ ọ, nwọn nwá ọ̀na ati ri
nkan gbámu li ẹnu rẹ̀, ki nwọn ki o le fi i
sùn.

## ORI 12.

O SI ṣe, nigbati ainiye ijọ enia pejọ pọ̀,
tobẹ̃ ti nwọn ntẹ̀ ara wọn mọlẹ, o tète
bẹ̀rẹ si iwi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe, Ẹ ma
kiyesi iwukara awọn Farisi, ti iṣe agaba-
gebe.
2 Kò si ohun ti a dè mọlẹ, ti a kì yio si
fihàn; tabi ti o lumọ́, ti a kì yio mọ̀.
3 Njẹ ohunkohun ti ẹnyin sọ li òkunkun,
ni gbangba li a o gbé gbọ́; ati ohun ti
ẹnyin sọ si etí ni ìkọkọ, lori orule li a o gbé
wasu rẹ̀.
4 Ki emi ki o si wi fun ẹnyin ọrẹ́ mi, Ẹ
máṣe bẹ̀ru awọn ti ipa ara enia kú, lẹhin
eyini nwọn kò li eyi ti nwọn le ṣe mọ́.
5 Ṣugbọn emi o wi ẹniti ẹnyin o bẹ̀ru
fun nyin: Bẹ̀ru ẹniti o ba pa-ni tan, ti o
si li agbara ati wọ́-ni lọ si ọrun apadi; lõtọ
ni emi wi fun nyin, Ki ẹnyin ki o bẹ̀ru rẹ̀.
6 Ologoṣẹ marun ki a ntà li owo idẹ
wẹ́wẹ meji, ọkan kò ṣe igbagbé ninu wọn
niwaju Ọlọrun?
7 Ṣugbọn gbogbo iru-iyirun ori nyin li a
kà pe ṣanṣan. Njẹ ki ẹnyin ki o máṣe
bẹ̀ru: ẹnyin ni iye lori jù ologoṣẹ pipọ lọ.
8 Emi wi fun nyin pẹlu, Ẹnikẹni ti o ba
jẹwọ mi niwaju enia, Ọmọ-enia yio si jẹwọ
rẹ̀ niwaju awọn angeli Ọlọrun:
9 Ṣugbọn ẹniti o ba sẹ́ mi niwaju enia, a
o sẹ́ ẹ niwaju awọn angeli Ọlọrun.
10 Ati ẹnikẹni ti o ba sọ̀rọ òdi si Ọmọ-
enia, a o dari rẹ̀ jì i: ṣugbọn ẹnikẹni ti o
ba sọ̀rọ òdi si Ẹmí Mimọ́, a kì yio dari rẹ̀
jì i.
11 Nigbati nwọn ba si mu nyin lọ sinu
sinagogu, ati si ọdọ awọn olori, ati ala-
gbara, ẹ máṣe ronu pe, bawo, tabi ohùn
kili ẹnyin o da, tabi kili ẹnyin o wi:
12 Nitori Ẹmí Mimọ́ yio kọ́ nyin ni
wakati kanna li ohun ti ẹnyin o wi.
13 ¶ Ọkan ninu awujọ si wi fun u pe,
Olukọni, sọ fun arakọnrin mi ki o pín mi
li ogún ilẹ.
14 O si wi fun u pe, Ọkọnrin yi, tali o fi
mi jẹ onidajọ tabi ojuwa fun nyin?
15 O si wi fun wọn pe, Ẹ mã ṣọra, ki
ẹnyin ki o si ma kiyesi ojukòkoro: nitori
ẹmí enia kì iduro nipa ọ̀pọ ohun ti o ni.
16 O si pa owe kan fun wọn, wipe, Ilẹ
ọkọnrin kan ọlọrọ̀ so eso ọ̀pọlọpọ:
17 O si rò ninu ara rẹ̀, wipe, Emi o ti
ṣe, nitoriti emi kò li àye nibiti emi o gbé
kó eso mi jọ si?
18 O si wipe, Eyi li emi o ṣe: emi o wó
aká mi palẹ, emi o si kọ́ eyi ti o tobi; nibẹ̀
li emi o gbé tò gbogbo eso ati ọrọ̀ mi jọ si.
19 Emi o si wi fun ọkàn mi pe, Ọkàn,
iwọ li ọrọ̀ pipọ ti a tò jọ fun ọ̀pọ ọdún;
mu irọra rẹ, mã jẹ, mã mu, si mã yọ̀.
20 Ṣugbọn Ọlọrun wi fun u pe, Iwọ
aṣiwere, li alẹ yi li a o bère ọkàn rẹ lọwọ
rẹ: njẹ titani nkan wọnni yio ha ṣe, ti iwọ
ti npèse silẹ?
21 Bẹ̃ li ẹniti o tò iṣura jọ fun ara rẹ̀, ti
kò si li ọrọ̀ nipa ti Ọlọrun.
22 ¶ O si wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe,
Nitori eyi li emi ṣe nwi fun nyin pe, ẹ
máṣe rònu fun ẹmí nyin pe, kili ẹnyin o
jẹ; ati fun ara nyin pe, kili ẹnyin o ma fi
bora.
23 Ẹmí jù onjẹ lọ, ara si jù aṣọ lọ.
24 Ki ẹnyin ki o kiyesi awọn ìwo: nwọn
kì ifọnrugbin, bẹ̃ni nwọn ki iká; nwọn kò
li aká, bẹ̃ni nwọn kò li abà; Ọlọrun sá
mbọ́ wọn: melomelo li ẹnyin yàtọ jù ẹiyẹ
lọ?
25 Ati tani ninu nyin nipa ìronu ti o le
fi igbọnwọ kan kún ọjọ aiyé rẹ̀?
26 Bi ẹnyin kò le ṣe eyi ti o kere, ẽṣe ti
ẹnyin fi nronu iyokù?
27 Ki ẹnyin ki o kiyesi awọn lili bi
nwọn ti ndàgba: nwọn kì iṣiṣẹ, nwọn kì
iranwu; ṣugbọn ki emi wi fun nyin, a kò
wọ̀ Solomoni li ọṣọ́ ni gbogbo ogo rẹ̀ to
ọkan ninu wọnyi.
28 Njẹ bi Ọlọrun ba wọ̀ koriko igbẹ́ li

Digitized by Google

aṣọ tobẽ, ti o wà ninu igbẹ́ loni, ti o di
ọla ti a o si já a sọ sinu ẹbu; melomelo
ni yio wọ̀ nyin li aṣọ, Ẹnyin onikekere
igbagbọ́?
29 Ki ẹnyin ki o máṣe wipe, kili ẹnyin
o jẹ tabi kili ẹnyin o mu, ki ẹnyin ki o má
si ṣiyemeji.
30 Nitori ohun gbogbo wọnyi ni orile-
ède aiye nwá kiri: Baba nyin ti mbẹ li
ọrun si mọ̀ pe, ẹnyin nfẹ nkan wọnyi.
31 ¶ Ṣugbọn ki ẹnyin ki o kuku ma wá
ijọba Ọlọrun; gbogbo nkan wọnyi li a o si
fi kún u fun nyin.
32 Má bẹ̀ru, agbo kekere; nitori didùn
inu Baba nyin ni lati fi ijọba fun nyin.
33 Ẹ tà ohun ti ẹnyin ni, ki ẹnyin ki o
si tọrẹ ãnu; ki ẹnyin ki o si pèse àpo fun
ara nyin, ti a kì ilò gbó, iṣura li ọrun ti kì
itán, nibiti olè kò le sunmọ, ati ibiti kò-
koro kì iba a jẹ,
34 Nitori nibiti iṣura nyin gbé wà, nibẹ̀
li ọkàn nyin yio gbé wà pẹlu.
35 Ẹ di amure nyin, ki iná nyin ki o si
ma tàn;
36 Ki ẹnyin tikara nyin ki o dabi ẹniti
nreti oluwa wọn, nigbati on o pada ti ibi
iyawo de; nigbati o ba de, ti o si kànkun,
ki nwọn ki o le ṣí i silẹ fun u lọgan.
37 Ibukun ni fun irú awọn ọmọ-ọdọ
bawọnni, nigbati oluwa na ba de ti yio ba
ki nwọn ki o ma ṣọna: lõtọ ni mo wi fun
nyin, yio si di ara rẹ̀ li amure, yio si mu
wọn joko lati jẹun, yio si jade wá lati ṣe
iranṣẹ fun wọn.
38 Bi o ba si de nigba iṣọ keji, tabi ti o
si de nigba iṣọ kẹta, ti o si ba wọn bẽ,
ibukun ni fun awọn ọmọ-ọdọ wọnni.
39 Ki ẹnyin ki o si kiyesi eyi pe, bãle
na iba mọ̀ wakati ti olè yio wá, on iba ma
ṣọna, kì ba ti jẹ ki a lu ile on já.
40 Nitorina ki ẹnyin ki o mura pẹlu:
Nitori Ọmọ-enia mbọ̀ ni wakati ti ẹnyin
kò daba.
41 ¶ Peteru si bi i pe, Oluwa, iwọ pa
owe yi fun awa nikan, tabi fun gbogbo
enia?
42 Oluwa si dahùn wipe, Tani olõtọ ati
ọlọ́gbọn iriju na, ti oluwa rẹ̀ fi jẹ olori
agbo ile rẹ̀, lati ma fi ìwọn onjẹ wọn fun
wọn li akokò?
43 Ibukun ni fun ọmọ-ọdọ na, nigbati
oluwa rẹ̀ de, ti yio ba a ki o ma ṣe bẽ.
44 Lõtọ ni mo wi fun nyin, yio si fi i jẹ
olori ohun gbogbo ti o ni.
45 Ṣugbọn bi ọmọ-ọdọ na ba si wi li
ọkàn rẹ̀ pe, Oluwa mi yẹ̀ igba atibọ̀ rẹ̀
sẹhin; ti o si bẹ̀rẹ si ilù awọn iranṣẹ ọmọ-
kọnrin ati iranṣẹ ọmọbirin, ti o si bẹ̀rẹ si
ijẹ ati si imu amupara;
46 Oluwa ọmọ-ọdọ na yio de li ọjọ ti kò
reti rẹ̀, ati ni wakati ti kò daba, yio si jẹ ẹ
niyà gidigidi, yio si yàn ipò rẹ̀ pẹlu awọn
alaigbagbọ́.
47 Ati ọmọ-ọdọ na, ti o mọ̀ ifẹ oluwa rẹ̀,
ti kò si mura, ti kò si ṣe bi ifẹ tirẹ̀, on li a
o nà pipọ.
48 Ṣugbọn eyi ti kò mọ̀, ti o ṣe iṣe ti o
yẹ si ìlu, on li a o lù niwọn. Nitori gbo-
gbo ẹniti a fun ni pipọ̀, lọdọ rẹ̀ li a o gbé
bère pipọ: lọdọ ẹniti enia ba gbé fi pipọ si,
lọdọ rẹ̀ li a o gbé bère si i.
49 ¶ Iná li emi wá lati fọ̀n si aiye; kili
emi nfẹ bi a ba ti da a ná?
50 Ṣugbọn emi ni baptismu kan ti a o fi
baptisi mi; ara ti ni mi to titi yio fi pari!
51 Ẹnyin ṣebi alafia li emi wá fi si aiye?
ki emi ki o wi fun nyin, Bẽkọ; ki a sá
kuku pe iyapa:
52 Nitori lati isisiyi lọ, enia marun yio
wà ni ile kanna ti a o yà ni ipa, mẹta si
meji, ati meji si mẹta.
53 A o yà baba ni ipa si ọmọ rẹ̀ ọkọnrin,
ati ọmọkọnrin si baba; iya si ọmọbirin rẹ̀,
ati ọmọbirin si iya rẹ̀; iyakọ si iyawo rẹ̀,
ati iyawo si iyakọ rẹ̀.
54 ¶ O si wi fun awọn enia pẹlu pe,
Nigbati ẹnyin ba ri awọsanma kan ti o ṣú
ni ìha ìwọ-õrùn, ọgan ẹnyin a ni, Ọwara
òjo mbọ̀; a si ri bẽ.
55 Nigbati afẹfẹ gusù ba nfẹ, ẹnyin a ni,
Oru yio mu; a si ṣẹ.
56 Ẹnyin agabagebe ẹnyin le moye oju
ọrun ati ti aiye; ẽhatiṣe ti ẹnyin kò le mọ̀
akokò yi?
57 Tabi ẽhatiṣe ti ẹnyin tikara nyin kò
fi rò ohun ti o tọ́?
58 ¶ Nigbati iwọ ba mbá ọtá rẹ lọ sọdọ
olori, mura li ọ̀na ki a le gbà ọ lọwọ rẹ̀; ki
o máṣe fi ọ le onidajọ lọwọ, ki onidajọ
máṣe fi ọ le ẹṣọ lọwọ, on a si tì iwọ sinu
tubu.
59 Ki emi ki o wi fun ọ, iwọ kì yio jade
kuro nibẹ̀, titi iwọ o fi san owo kan iyokù.

## ORI 13.

AWỌN kan wà li akokò na ti o sọ ti awọn
ara Galili fun u, ẹ̀jẹ ẹniti Pilatu dàpọ
pẹlu ẹbọ wọn.
2 Jesu si dahùn o wi fun wọn pe, Ẹnyin
ṣebi awọn ara Galili wọnyi ṣe ẹlẹṣẹ jù gbo-
gbo awọn ara Galili lọ, nitoriti nwọn jẹ irú
iya bawọnni?

Digitized by Google

3 Ki emi ki o wi fun nyin, Bẹ̃kọ: biko-
ṣepe ẹnyin ronupiwada, ẹnyin na gbogbo
yio ṣegbé bẹ̃ gẹgẹ.
4 Tabi awọn mejidiliogun, ti ile-iṣọ ni
Siloamu wólu, ti o si pa wọn, ẹnyin ṣebi
nwọn ṣe ẹlẹṣẹ jù gbogbo awọn enia ti mbẹ̀
ni Jerusalemu lọ?
5 Ki emi ki o wi fun nyin, Bẹ̃kọ: biko-
ṣepe ẹnyin ronupiwada, ẹnyin na gbogbo
yio ṣegbé bẹ̃ gẹgẹ.
6 ¶ O si pa owe yi fun wọn pe; Ọkọnrin
kan ni igi ọpọtọ kan ti a gbìn si ọgbà ajara
rẹ̀; o si de, o nwá eso lori rẹ̀, kò si ri nkan.
7 O si wi fun oluṣọgba rẹ̀ pe, Sawò o,
lati ọdún mẹta yi li emi ti nwá iwò eso
lori igi ọpọtọ yi, emi kò si ri nkan: ké e
lulẹ; ẽṣe ti o fi ngbilẹ lasan?
8 O si dahùn o wi fun u pe, Oluwa,
jọwọ rẹ̀ li ọdún yi pẹlu, titi emi o fi tú ilẹ
idi rẹ̀ yiká, titi emi o si fi bu ilẹdu si i:
9 Bi o ba si so eso, gẹgẹ: bi kò ba si so,
njẹ lẹhin eyini ki iwọ ki o ke e lulẹ.
10 O si nkọ́ni ninu sinagogu kan li ọjọ
isimi.
11 ¶ Si kiyesi i, obirin kan wà nibẹ̀ ti o
ni ẹmí ailera, lati ọdún mejidilogun wá,
ẹniti o tẹ̀ tan, ti kò le gbé ara rẹ̀ soke bi o
ti wù ki o ṣe.
12 Nigbati Jesu ri i, o pè e si ọdọ, o si
wi fun u pe, Obirin yi, a tú ọ silẹ lọwọ
ailera rẹ.
13 O si fi ọwọ́ rẹ̀ le e: lojukanna a si ti
sọ ọ di titọ́, o si yìn Ọlọrun logo.
14 Olori sinagogu fi ibinu dahùn, nitori
ti Jesu mu-ni lara da li ọjọ isimi, o si wi
fun awọn enia pe, Ijọ mẹfa ni mbẹ ti a fi
iṣiṣẹ: ninu wọnni ki ẹnyin ki o wá ki a ṣe
dida ara nyin, ki o máṣe li ọjọ isimi.
15 Nigbana li Oluwa dahùn, o si wi fun
u pe, Iwọ agabagebe, olukuluku nyin ki
itú malu tabi kẹtẹkẹtẹ rẹ̀ nibuso, kì si ifà
a lọ lati mu omi li ọjọ isimi?
16 Kò si yẹ ki a tú obirin yi ti iṣe ọmọ-
birin Abrahamu silẹ ni ìde yi li ọjọ isimi,
ẹniti Satani ti dè, sawò o, lati ọdún meji-
dilogun yi wá?
17 Nigbati o si wi nkan wọnyi, oju tì
gbogbo awọn ọtá rẹ̀: gbogbo awọn enia si
yọ̀ fun ohun ogo gbogbo ti o ṣe lati ọwọ́ rẹ̀
wá.
18 ¶ O si wipe, Kini ijọba Ọlọrun jọ?
kili emi o si fi wé?
19 O dabi wóro kan irugbin eweko
(mustardi), ti ọkọnrin kan mu, ti o si sọ
sinu ọgbà rẹ̀; ti o si hù, o si di igi nla;
ẹiyẹ oju ọrun si wá lati ma gbé ori ẹka rẹ̀.
20 O si tún wipe, Kili emi iba fi ijọba
Ọlọrun wé?
21 O dabi iwukara, ti obirin kan mu, ti
o fi sinu iyẹfun oṣuwọn mẹta, titi gbogbo
rẹ̀ o fi di wiwu.
22 O si nlà arin ilu-nla ati iletò lọ, o
nkọ́ni o si nrìn lọ si ìha Jerusalemu.
23 Ẹnikan si bi i pe, Oluwa, diẹ ha li
awọn ti a o gbalà? O si wi fun wọn pe,
24 ¶ Ẹ làkaka lati wọ̀ oju-ọ̀na koto:
nitori emi wi fun nyin, enia pipọ ni yio wá
ọ̀na ati wọ̀ ọ, nwọn kì yio si le wọle.
25 Nigbati bãle ile ba dide lẹkan fũ, ti
o ba si ti sé ilẹkun, nigbati ẹnyin o bẹ̀rẹ si
iduro lode, ti ẹnyin o ma kànkun, wipe,
Oluwa, Oluwa, ṣí i fun wa; on o si dahùn
wi fun nyin pe, Emi kò mọ̀ nyin nibiti
ẹnyin gbé ti wá:
26 Nigbana li ẹnyin o bẹ̀rẹ si iwi pe,
Awa ti njẹ, awa si ti nmu niwaju rẹ, iwọ si
kọ́ni ni igboro ilu wa.
27 On o si wipe, Emi wi fun nyin, emi
kò mọ̀ nyin nibiti ẹnyin gbè ti wá; ẹ lọ
kuro lọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ.
28 Ẹkún ati ipahin keke yio wà nibẹ̀,
nigbati ẹnyin o ri Abrahamu, ati Isaaki,
ati Jakọbu, ati gbogbo awọn woli, ni ijọba
Ọlọrun, ti a o si tì nyin sode.
29 Nwọn o si ti ìla-õrùn, ati ìwọ-õrùn
wá, ati lati ariwa, ati gusù wá, nwọn o si
joko ni ijọba Ọlọrun.
30 Sá si kiyesi i, awọn ara ẹ̀hin yio di ti
iwaju, awọn ara iwaju yio si di ti ẹ̀hin.
31 ¶ Li ọjọ na awọn kan ninu awọn
Farisi wá, nwọn si wi fun u pe, Jade, ki
iwọ ki o si lọ kuro nihinyi: nitori Herodu
yio pa ọ.
32 O si wi fun wọn pe, Ẹ lọ, ki ẹnyin ki
o si sọ fun kọlọkọlọ nì pe, Kiyesi i, emi nlé
awọn ẹmi ẽṣu jade, emi nṣe dida ara loni
ati lọla, ati ni ijọ kẹta emi o pé.
33 Ṣugbọn emi kò jẹ má rìn loni, ati
lọla, ati li ọtunla: kò le jẹ bẹ̃ pe woli
ṣegbé lẹhin ode Jerusalemu.
34 Jerusalemu, Jerusalemu, iwọ ti o pa
awọn woli, ti o si sọ okuta lù awọn ti a
rán si ọ pa; nigba melo li emi nfẹ iradọ bò
awọn ọmọ rẹ, bi agbebọ̀ ti iradọ bò awọn
ọmọ rẹ̀ labẹ apá rẹ̀, ṣugbọn ẹnyin kò fẹ!
35 Sawò o, a fi ile nyin silẹ fun nyin li
ahoro: lõtọ ni mo si wi fun nyin, Ẹnyin
kì yio ri mi, titi yio fi di akoko ti ẹnyin o
wipe, Olubukun li ẹniti o mbọ̀ wá li orukọ
Oluwa.

Digitized by Google

## ORI 14.

O SI ṣe, bi o ti wọ̀ ile ọkan ninu awọn olori Farisi lọ lati jẹun li ọjọ isimi, nwọn nṣọ ọ.

2 Si kiyesi i, ọkọnrin kan mbẹ niwaju rẹ̀ ti o li asunkun.

3 Jesu si dahùn o wi fun awọn amofin ati awọn Farisi pe, O ha tọ́ lati mu-ni lara da li ọjọ isimi?

4 Nwọn si dakẹ. O si mu u, o mu u lara da, o si jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ;

5 O si dahùn o wi fun wọn pe, Tani ninu nyin ti yio ni kẹtẹkẹtẹ tabi malu kan, ti o bọ sinu ihò, ti kì yio si fà a soke lojukanna li ọjọ isimi?

6 Nwọn kò si le da a li ohùn mọ́ si nkan wọnyi.

7 ¶ O si pa owe kan fun awọn ti a pè wa jẹun, nigbati o wò bi nwọn ti nyàn ipò ọlá; o si wi fun wọn pe,

8 Nigbati a ba ti ọdọ ẹnikan pè ọ wá si ibi iyawo, máṣe joko ni ipò ọlá; nitori bi a o ba pè ẹniti o li ọlá jù ọ lọ.

9 Nigbati ẹniti o pè ọ ati on ba de, a si wi fun ọ pe, Fun ọkọnrin yi li àye; iwọ a si ma fi itiju mu ipò ẹhin.

10 Ṣugbọn nigbati a ba pè ọ, lọ ki o si joko ni ipò ẹhin; nigbati ẹniti o pè ọ ba de, ki o le wi fun ọ pe, Ọrẹ́, bọ́ soke: nigbana ni iwọ o ni iyìn li oju awọn ti o ba ọ joko ti onjẹ.

11 Nitori ẹnikẹni ti o ba gbé ara rẹ̀ ga, a o rẹ̀ ẹ silẹ; ẹnikẹni ti o ba si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, a o si gbé e ga.

12 ¶ Nigbana li o si wi fun alase ti o pè e pe, Nigbati iwọ ba se àse ọsán, tabi àse alẹ, má pè awọn ọrẹ́ rẹ, tabi awọn arakọnrin rẹ, tabi awọn ibatan rẹ, tabi awọn aladugbo rẹ ọlọrọ̀; nitori ki nwọn ki o má ṣe pè ọ ẹ̀wẹ lati san ẹsan fun ọ.

13 Ṣugbọn nigbati iwọ ba se àse, pè awọn talakà, awọn alabùkù arùn, awọn amọkun, ati awọn afọju:

14 A o si busi i fun ọ; nitori nwọn kò le san a fun ọ: ṣugbọn a o san fun ọ li ajinde olõtọ.

15 ¶ Nigbati ọkan ninu awọn ti o ba a joko tì onjẹ gbọ́ nkan wọnyi, o wi fun u pe, Ibukun ni fun ẹniti yio jẹun ni ijọba Ọlọrun.

16 Nigbana li o wi fun u pe, Ọkọnrin kan se àse alẹ nla, o si pè enia pipọ:

17 O si rán ọmọ-ọdọ rẹ̀ ni wakati àse alẹ, ki o wi fun awọn ti a ti pè tẹlẹ pe, Ẹ wá; nitori ohun gbogbo ṣe tan.

18 Gbogbo wọn si bẹ̀rẹ li ohùn kan lati ma wawi. Ekini wi fun u pe, Emi rà ilẹ kan biri bayi, emi kò le ṣe ki nmá lọ iwò o: mo bẹ̀ ọ ki a ṣe gafara fun mi.

19 Ekeji si wipe, Emi rà ajaga malu marun, emi si nlọ lati dán wọn wò: mo bẹ̀ ọ ki a ṣe gafara fun mi.

20 Ẹkẹta si wipe, Emi gbeyawo, nitorina li emi kò fi le wá.

21 Nigbati ọmọ-ọdọ na pada de, o si sọ gbogbo nkan wọnyi fun oluwa rẹ̀. Nigbana ni bãle ile binu, o wi fun onṣẹ rẹ̀ pe, Jade lọ nisisiyi si igboro ilu, ati si abuja ọ̀na igboro ilu, ki o si mu awọn talakà, ati awọn alabùkù arùn, ati awọn amọkun, ati awọn afọju wá si ihinyi.

22 Ọmọ-ọdọ na si wipe, Oluwa, a ṣe bi o ti wi tan, àye si mbẹ sibẹ.

23 Oluwa si wi fun ọmọ-ọdọ na pe, Jade lọ si opópo, ati si ipa-ọ̀na ọgbà, ki o si rọ̀ wọn ki nwọn ki o wá, ki a le mu ile mi kún.

24 Ki emi wi fun nyin, Ẹnikẹni ninu awọn ti a ti pè, ki yio tọwò ninu àse alẹ mi.

25 ¶ Awọn enia pipọ mba a lọ: o si yipada, o si wi fun wọn pe,

26 Bi ẹnikan ba tọ̀ mi wá, ti kò korira baba rẹ̀, ati iya, ati aya, ati ọmọ, ati arakọnrin, ati arabirin, ati ẹmí ara rẹ̀ pẹlu, kò le ṣe ọmọ-ẹhin mi.

27 Ati ẹnikẹni ti kò ba si rù agbelebu rẹ̀, ki o mã tọ̀ mi lẹhin, kò le ṣe ọmọ-ẹhin mi.

28 Nitori tani ninu nyin ti npete ati kọ́ ile iṣọ, ti kì yio tète joko ki o ṣiro iye rẹ̀, bi on ni to ti yio fi pari rẹ̀.

29 Asiwa-asibọ, nigbati o ba fi ipilẹ ile sọlẹ tan, ti kò le pari rẹ̀ mọ́, gbogbo awọn ti o ri i a bẹ̀rẹ si ifi i ṣe ẹlẹyà,

30 Wipe, Ọkọnrin yi bẹ̀rẹ si ile ikọ́, kò le pari rẹ̀.

31 Tabi ọba wo ni nlọ lati ba ọba miran jà, ti kì yio tète joko, ki o gbèro bi yio le fi ẹgbarun padegun ẹniti nmu ẹgbawa bọ̀ wá kò on loju?

32 Tabi igbati onitọhun mbẹ li òkere, ki o rán ikọ̀ pe, ipinhun ilaja li on nfẹ.

33 Gẹgẹ bẹ̃ni, ẹnikẹni ti o wù ki o ṣe ninu nyin, ti kò ba kọ̀ ohun gbogbo ti o ni silẹ, kò le ṣe ọmọ-ẹhin mi.

34 ¶ Iyọ̀ dara: ṣugbọn bi iyọ̀ ba di obu, nibo li a o gbé fi i dùn?

35 Kò yẹ fun ilẹ, bẹ̃ni kò yẹ fun àtan; bikoṣepe ki a kó o danù. Ẹniti o ba li etí lati fi gbọ́ ki o gbọ́.

Digitized by Google

## ORI 15.

NIGBANA ni gbogbo awọn agbowode ati
ẹlẹṣẹ sunmọ ọ lati gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀.
2 Ati awọn Farisi ati awọn akọwe nkùn,
wipe, Ọkọnrin yi ngbà ẹlẹṣẹ, o si mba wọn
jẹun.
3 ¶ O si pa owe yi fun wọn, wipe,
4 Ọkọnrin wo ni ninu nyin, ti o ni ọgọ-
run agutan, bi o ba sọ ọkan nù ninu wọn,
ti kì yio fi mọkandilọgọrun iyokù silẹ ni
pápa, ti kì yio si tọsẹ eyi ti o nù lọ, titi
yio fi ri i?
5 Nigbati o si ri i tan, o gbé e le ejika rẹ̀,
o nyọ̀.
6 Nigbati o si de ile, o pè awọn ọrẹ́ ati
aladugbo rẹ̀ jọ, o nwi fun wọn pe, Ẹ ba mi
yọ̀; nitoriti mo ri agutan mi ti o ti nù.
7 Ki emi ki o wi fun nyin, gẹgẹ bẽli
ayọ̀ yio wà li ọrun lori ẹlẹṣẹ kan ti o ronu-
piwada, jù lori olõtọ mọkandilọgọrun lọ, ti
o ṣe alaini ironupiwada.
8 ¶ Tabi obirin wo li o ni fadaka mẹwa,
bi o ba sọ ọkan nù, ti kì yio tàn fitilà, ti
kì yio gbá ile, ti kì yio wá a gidigidi titi yio
fi ri i?
9 Nigbati o si ri i, o pè awọn ọrẹ́ ati
awọn aladugbo rẹ̀ jọ, o wipe, Ẹ ba mi yọ̀;
nitori mo ri fadakà ti mo ti sọnù.
10 Ki emi ki o wi fun nyin, gẹgẹ bẽli
ayọ̀ mbẹ niwaju awọn angeli Ọlọrun lori
ẹlẹṣẹ kan ti o ronupiwada.
11 ¶ O si wipe, Ọkọnrin kan li ọmọ-
kọnrin meji:
12 Eyi aburo ninu wọn wi fun baba rẹ̀
pe, Baba, fun mi ni ìwọn ogún ti o tori mi.
O si pín ohun ìni rẹ̀ fun wọn.
13 Kò si to ijọ melokan lẹhin eyi, eyi
ọmọkọnrin aburo kó ohun gbogbo ti o ni
jọ, o si mu ọ̀na àjo rẹ̀ pọn lọ si ilu òkere,
nibẹ̀ li o gbé ná gbogbo ini rẹ̀ ni inákuna.
14 Nigbati o si bà gbogbo rẹ̀ jẹ tan,
ìyan nla wá imu ni ilu na; o si bẹrẹ si idi
alaini.
15 O si lọ, o da ara rẹ̀ pọ̀ mọ́ ọlọ̀tọ kan
ni ilu na; on si rán a lọ si oko rẹ̀ lati ṣọ
ẹlẹdẹ.
16 Ayọ̀ ni iba fi jẹ onjẹ ti awọn ẹlẹdẹ njẹ
li ajẹyó: ẹnikẹni kò si fifun u.
17 Nigbati oju rẹ̀ walẹ, o ni, Awọn ala-
gbaṣe baba mi melomelo li o ni onjẹ ajẹyó,
ati ajẹtì, emi si nkú fun ebi!
18 Emi o dide, emi o tọ̀ baba mi lọ, emi
o si wi fun u pe, Baba, emi ti dẹṣẹ si ọrun,
ati niwaju rẹ,
19 Emi kò si yẹ ti a ba ma pè li ọmọ rẹ
mọ́: fi mi ṣe bi ọkan ninu awọn alagbaṣe
rẹ.
20 O si dide, o si tọ̀ baba rẹ̀ lọ. Ṣugbọn
nigbati o ti wà li òkere, baba rẹ̀ ri i, ãnu
ṣe e, o si sure, o rọ̀mọ́ ọ li ọrùn, o si fi ẹnu
kò o li ẹnu.
21 Ọmọ na si wi fun u pe, Baba, emi ti
dẹṣẹ si ọrun, ati niwaju rẹ, emi kò si yẹ ti
a ba ma pè li ọmọ rẹ mọ́.
22 Ṣugbọn baba wi fun awọn ọmọ-ọdọ
rẹ̀ pe, Ẹ mu ãyo aṣọ igunwa wá, ki ẹ fi wọ̀
ọ; ẹ si fi oruka bọ̀ ọ lọwọ, ati bàta si ẹsẹ
rẹ̀:
23 Ẹ si mu ẹgbọ̀rọ malu abọpa wá,
ki ẹ si pa a; ki a ma jẹ, ki a si ma ṣe
ariya:
24 Nitori ọmọ mi yi ti kú, o si tún
yè; o ti nù, a si ri i. Nwọn si bẹrẹ si
iṣe ariya.
25 Ṣugbọn ọmọ rẹ̀ eyi ẹgbọ́n ti wà li
oko: bi o si ti mbọ̀, ti o sunmọ eti ile, o
gbọ́ orin on ijó.
26 O si pè ọkan ninu awọn ọmọ-ọdọ
wọn, o bère pe, kili ã mọ̀ nkan wọnyi
si?
27 O si wi fun u pe, Aburo rẹ de; baba
rẹ si pa ẹgbọ̀rọ malu abọpa, nitoriti o ri i
pada li alafia ati ni ilera.
28 O si binu, o kọ̀ lati wọle; baba rẹ̀ si
jade, o wá ìṣipẹ fun u.
29 O si dahùn o wi fun baba rẹ̀ pe, Ki-
yesi i, lati ọdún melo yi li emi ti nsìn ọ,
bẽli emi kò si ru ofin rẹ nigba kan ri: iwọ
kò si ti ifi ọmọ ewurẹ kan fun mi, ki emi
ki o fi ba awọn ọrẹ́ mi ṣe ariya:
30 Ṣugbọn bi ọmọ rẹ yi si ti de, ẹniti o
fi panṣaga run ọrọ̀ rẹ, iwọ si ti pa ẹgbọ̀rọ
malu abọpa fun u.
31 O si wi fun u pe, Ọmọ, titi ni iwọ
mbẹ lọdọ mi, ohun gbogbo ti mo ni tirẹ ni
iṣe.
32 O yẹ ki a ma ṣe ariya ki a si yọ̀:
nitori aburo rẹ yi ti kú, o si tún yè; o ti
nù, a si ri i.

## ORI 16.

OSI wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe, Ọkọn-
rin kan ọlọrọ̀ ti wà, ti o ni iriju kan;
on na ni nwọn fi sùn u pe, o ti nfi ọrọ̀ rẹ̀
ṣòfo.
2 Nigbati o si pè e, o wi fun u pe, Ẽṣe ti
emi fi ngbọ́ eyi nitori rẹ? ṣiro iṣẹ iriju rẹ;
nitori bọya iwọ kì yio ṣe iriju pẹ mọ́.
3 Iriju na si wi ninu ara rẹ̀ pe, Ewo li
emi o ṣe? nitoriti Oluwa mi gbà iṣẹ iriju

Digitized by Google

lọwọ mi: emi kò le wàlẹ; lati ṣagbe oju
ntì mi.
4 Mo mọ̀ bi emi o ti ṣe, nigbati a ba mu
mi kuro nibi iṣẹ iriju, ki nwọn ki o le gbà
mi sinu ile wọn.
5 Bẹ̃li o pè olukuluku awọn ajigbese
oluwa rẹ̀ sọdọ rẹ̀, o si bi ekini pe, Elo ni
iwọ jẹ oluwa mi?
6 O si wipe, Ọgọrun oṣuwọn oróro. O
si wi fun u pe, Mu iwe rẹ, ki iwọ ki o si
joko nisisiyi, ki o kọwe ti adọta.
7 Nigbana li o si bi ẹnikeji pe, Elo ni
iwọ jẹ? On si wipe, Ọgọrun oṣuwọn ali-
kama. O si wi fun u pe, Mu iwe rẹ, ki o
si kọwe ti ọgọrin.
8 Oluwa rẹ̀ si yìn alaiṣõtọ iriju na, ni-
toriti o fi ọgbọ́n ṣe e: awọn ọmọ aiye yi
sá gbọ́n ni iran wọn jù awọn ọmọ imọlẹ lọ.
9 Emi si wi fun nyin, ẹ fi mammoni
alaiṣõtọ yàn ọrẹ́ fun ara nyin; nigbati yio
ba yẹ̀, ki nwọn ki o le gbà nyin si ibujoko
wọn titi aiye.
10 Ẹniti o ba ṣe olõtọ ni kikini, o ṣe
olõtọ ni pipọ pẹlu: ẹniti o ba si ṣe alaiṣõtọ
ni kikini, o ṣe alaiṣõtọ ni pipọ pẹlu.
11 Njẹ ẹnyin iba má ṣe olõtọ ni mam-
moni alaiṣõtọ, tani iba fi ọrọ̀ ṣú nyin?
12 Ẹnyin iba má si ṣe olõtọ li eyi ti iṣe
ti ẹlomiran, tani iba fun nyin li eyi ti iṣe
ti ẹnyin tikara nyin?
13 ¶ Kò si iranṣẹ kan ti o le sìn baba
meji: ayaṣebi yio yàn ọkan ni iposi, ki o
si fẹ ẹnikeji; tabi ki o fi ara mọ́ ọkan, ki
o si takete si ẹnikeji. Ẹnyin kò le sìn
Ọlọrun on mammoni.
14 Ati awọn Farisi pẹlu, ti nwọn li oju-
kòkoro gbọ́ gbogbo nkan wọnyi, nwọn si
yọ-sùti si i.
15 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin li awọn
ti idare fun ara nyin niwaju enia; ṣugbọn
Ọlọrun mọ̀ ọkàn nyin: nitori eyi ti a gbé
niyìn lọdọ enia, on li o jẹ irira niwaju
Ọlọrun.
16 Ofin ati woli mbẹ titi di igba Johan-
nu: lati igbana wá li a ti nwasu ijọba
Ọlọrun, olukuluku enia ni si nlàkaka lati
wọ̀ inu rẹ̀.
17 O rọrun fun ọrun on aiye lati fò lọ,
jù ki ṣonṣo kan ti ofin ki o yẹ̀.
18 Ẹnikẹni ti o ba kọ̀ aya rẹ̀ silẹ, ti o si
gbé omiran ni iyawo, o ṣe panṣaga: ati
ẹnikẹni ti o si gbé ẹniti ọkọ rẹ̀ kọ̀ silẹ ni
iyawo, o ṣe panṣaga.
19 ¶ Ọkọnrin kan ọlọrọ̀ ti wà, ti o nwọ̀
aṣọ elesè àluko ati aṣọ àla daradara, a si ma
jẹ didùndidun lojojumọ́:
20 Alagbe kan si wà ti a npè ni Lasaru,
ti nwọn ima gbé wá kalẹ lẹba ọ̀na ile rẹ̀, o
kún fun õju,
21 On a si ma fẹ ki a fi ẹrún ti o ti ori
tabili ọlọrọ̀ bọ silẹ bọ́ on: awọn ajá si de,
nwọn si fá a li õju lá.
22 O si ṣe, nigbati alagbe kú, a si ti ọwọ́
awọn angeli gbé e lọ si àiya Abrahamu:
ọlọrọ̀ na si kú pẹlu, a si sin i;
23 Li ọrun apadi li o gbé oju rẹ̀ soke, o
mbẹ ninu iṣẹ oró, o si ri Abrahamu li òkere,
ati Lasaru li àiya rẹ̀.
24 O si ke, o wipe, Baba Abrahamu,
ṣãnu fun mi, ki o si rán Lasaru, ki o fi
orika rẹ̀ bọmi, ki o si fi tù mi li ahọn;
nitori emi nṣíṣẹ oró ninu ọwọ́ iná yi.
25 Ṣugbọn Abrahamu wi fun u pe, Ọmọ,
ranti pe, nigbati iwọ mbẹ li aiye iwọ ti
gbà ohun rere tirẹ tan, ati Lasaru ohun
buburu: ṣugbọn nisisiyi ara rọ̀ ọ, iwọ si
nṣíṣẹ oró.
26 Ati pẹlu gbogbo eyi, ọgbun nla li a
fi da awa ati ẹnyin lagbedemeji: awọn ti
nfẹ, kò le rekọja si nyin lati ìhin lọ;
awọn ti si nfẹ, kò le rekọja si wa lati
ibẹ̀ wá.
27 O si wipe, Njẹ mo bẹ̀ ọ, baba, ki iwọ
ki o le rán a lọ si ile baba mi:
28 Nitori mo ni arakọnrin marun; ki o
le rò fun wọn, ki nwọn ki o má ba wá si
ibi ìṣẹ oró yi pẹlu.
29 Abrahamu si wi fun u pe, Nwọn ni
Mose ati awọn woli; ki nwọn ki o gbọ́
wọn.
30 O si wi fun u pe, Bẹ̃kọ, baba Abra-
hamu: ṣugbọn bi ẹnikan ba ti inu okú tọ̀
wọn lọ, nwọn o ronupiwada.
31 O si wi fun u pe, Bi nwọn kò ba gbọ́
Mose ati awọn woli, nwọn kì yio yi ọkàn
pada bi ẹnikan tilẹ ti inu okú dide.

## ORI 17.

NIGBANA li o wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
pe, Ko le ṣe ki ohun ikọsẹ̀ ma de:
ṣugbọn egbé ni fun u, nipasẹ ẹniti o ti
wá!
2 Iba san fun u ki a so ọlọ mọ́ ọ li ọrùn,
ki a si gbé e jù sinu okun, jù ki o mu ọkan
ninu awọn kekere wọnyi kọsẹ̀.
3 ¶ Ẹ ma kiyesi ara nyin: bi arakọnrin
rẹ ba ṣẹ̀ ọ, ba a wi; bi o ba si ronupiwada,
dari jì i.
4 Bi o ba ṣẹ̀ ọ li ẹrinmeje li õjọ, ti o si
pada si ọ li ẹrinmeje li õjọ pe, Mo ronupí-
wada; iwọ dari jì i.

Digitized by Google

5 Awọn aposteli si wi fun Oluwa pe,
Busi igbagbọ́ wa,
6 Oluwa si wipe, Bi ẹnyin ba ni igbagbọ́
bi wóro kan irugbin eweko mustardi, ẹnyin
le wi fun igi sikamine yi pe, Ki a fà ọ tú ti
gbòngbo, ki a si gbìn ọ sinu okun ; yio si
gbọ́ ti nyin.
7 Ati tani ninu nyin, ti o li ọmọ-ọdọ, ti
o ntulẹ, tabi ti o mbọ́ ẹran, ti yio wi fun u
nigbati o ba ti oko de pe, Lọ ijoko lati
jẹun ?
8 Ti kì yio kuku wi fun u pe, Mura,
pèse ohun ti emi o jẹ, si di amure, ki iwọ
ki o mã ṣe iranṣẹ fun mi, titi emi o fi jẹ ti
emi o fi mu tan ; lẹhin eyini ni iwọ o si jẹ,
ti iwọ o si mu ?
9 On ama dupẹ lọwọ ọmọ-ọdọ na, ni-
toriti o ṣe ohun ti a wi fun u ? emi kò rò
bẽ.
10 Gẹgẹ bẹ̃li ẹnyin, nigbati ẹnyin ba si
ṣe ohun gbogbo ti a wi fun nyin tan, ki
ẹnyin ki o wipe, Alailere ọmọ-ọdọ ni wa :
eyi ti iṣe iṣẹ isin wa li awa ṣe.
11 ¶ O si ṣe, nigbati o nlọ si Jerusalemu,
o kọja lọ larin Samaria on Galili.
12 Bi o si ti nwọ̀ inu iletò kan lọ, awọn
ọkọnrin adẹtẹ̀ mẹwa pade rẹ̀, nwọn duro li
òkere :
13 Nwọn si nahùn soke, wipe, Jesu,
Baba, ṣãnu fun wa.
14 Nigbati o ri wọn, o wi fun wọn pe,
Ẹ lọ ifi ara nyin hàn fun awọn alufa. O
si ṣe, bi nwọn ti nlọ, nwọn si di mimọ́.
15 Nigbati ọkan ninu wọn ri pe on di
mimọ́, o pada sẹhin, o si fi ohùn rara yìn
Ọlọrun logo,
16 O si wolẹ lẹba ẹsẹ rẹ̀, o ndupẹ fun u :
ara Samaria ni si iṣe.
17 Jesu si dahùn wipe, Awọn mẹwa ki
a sọdi mimọ́ ? Awọn mẹsan iyokù ha dà ?
18 A ko ri ẹnikan ti o pada wá fi iyìn fun
Ọlọrun, bikoṣe alejò yi ?
19 O si wi fun u pe, Dide, ma ba tirẹ
lọ : igbagbọ́ rẹ mu ọ lara da.
20 ¶ Nigbati awọn Farisi bi i pe, nigba-
wo ni ijọba Ọlọrun yio de, o da wọn li
ohùn wipe, Ijọba Ọlọrun ki iwá pẹlu àmi :
21 Bẹ̃ni nwọn kì yio wipe, Kiyesi i ni-
hin ! tabi kiyesi i lọhun ! sawò o, ijọba
Ọlọrun mbẹ ninu nyin.
22 O si wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe,
Ọjọ mbọ̀, nigbati ẹnyin o fẹ lati ri ọjọ kan
ninu ọjọ Ọmọ-enia, ẹnyin kì yio si ri i.
23 Nwọn o si wi fun nyin pe, Wò nihin ;
tabi wò lọhun : ẹ má tẹ̀le wọn, ẹ máṣe ba
wọn lọ.
24 Nitori gẹgẹ bi manamana, ti ikọ li
apakan labẹ ọrun, ti isi mọlẹ li apa keji
labẹ ọrun : bẹ̃li Ọmọ-ẹnia yio si ri li ọjọ
rẹ̀.
25 Ṣugbọn kò le tète ṣaima jìya ohun
pipọ, ki a si kọ̀ ọ lọdọ iran yi.
26 Bi o si ti ri nigba ọjọ Noa, bẹ̃ni yio
si ri nigba ọjọ Ọmọ-enia.
27 Nwọn njẹ, nwọn nmu, nwọn ngbe-
yawo, a si nfunni ni iyawo, titi o fi di ọjọ
ti Noa wọ̀ inu ọkọ̀ lọ, kíkun omi si de, o
run wọn gbogbo.
28 Ati gẹgẹ bi o ti ri nigba ọjọ Loti ;
nwọn njẹ, nwọn nmu, nwọn nrà, nwọn
ntà, nwọn ngbìn, nwọn nkọle ;
29 Ṣugbọn li ọjọ na gan ti Loti jade
kuro ni Sodomu, o rọ̀jo iná ati okuta iná ti
ọrun wá, o si run wọn gbogbo.
30 Gẹgẹ bẹ̃ni yio ri li ọjọ na nigbati a o
fi Ọmọ-enia hàn.
31 Li ọjọ na, ẹniti o ba wà lori àja, ti
ẹrù rẹ̀ mbẹ ni ile, ki o máṣe sọkalẹ wá lati
mu u : ati ẹniti o si wà li oko, ki o má si
ṣe pada sẹhin.
32 Ranti aya Loti.
33 Ẹnikẹni ti o ba nwá ati gbà ẹmi rẹ̀ là
yio sọ ọ nù ; ẹnikẹni ti yio si sọ ọ nù yio
gbà a là.
34 Mo wi fun nyin, li oru ọjọ na, enia
meji yio wà lori akete kan ; a o mu ọkan,
a o si fi ekeji silẹ.
35 Enia meji yio si ma lọ̀ ọlọ pọ̀ ; a o
mu ọkan, a o si fi ekeji silẹ.
36 Enia meji yio wà li oko ; a o mu
ọkan, a o si fi ekeji silẹ.
37 Nwọn si da a lohùn, nwọn bi i pe,
Nibo, Oluwa ? O si wi fun wọn pe, Nibi-
kibi ti okú ba gbé wà, nibẹ̀ ni idì ikojọ pọ̀
si.

## ORI 18.

O SI pa owe kan fun wọn nitori eyiyi pe,
o yẹ ki a mã gbadura nigbagbogbo,
ati laiṣe ãrẹ̀ ;
2 Wipe, Onidajọ kan wà ni ilu kan, ti
kò bẹru Ọlọrun, ti kò si ṣe ojusaju enia :
3 Opó kan si wà ni ilu na ; o si ntọ̀ ọ
wá, wipe, Gbẹsan mi lara ọtá mi.
4 Kò si ṣu si i nigba ọ̀sa kan : ṣugbọn
nikẹhin o wi ninu ara rẹ̀ pe, Bi emi kò tilẹ
bẹru Ọlọrun, ti emi kò ṣe ojusaju enia ;
5 Ṣugbọn nitori ti opó yi nyọ mi lẹnu,
emi o gbẹsan rẹ̀, nitori ki o má ba fi wíwa
rẹ̀ nigbakugba da mi lagã.
6 Oluwa si wipe, Ẹ gbọ́ bi alaiṣòtọ oni-
dajọ ti wi.

7 Ọlọrun kì yio ha gbẹsan awọn ayanfẹ rẹ̀, ti nfi ọsán ati oru kigbe pè e, bi o tilẹ duro pẹ lati da wọn lohùn nigba ọ̀sa kan ?

8 Mo wi fun nyin, yio gbẹsan wọn kánkán. Ṣugbọn nigbati Ọmọ-enia ba de, yio ha bá igbagbọ́ li aiye ?

9 O si pa owe yi fun awọn kan ti nwọn gbẹkẹle ara wọn pe, awọn li olododo, ti nwọn si ngàn awọn ẹlomiran:

10 Pe, Awọn ọkọnrin meji lọ si tempili lati gbadura; ọkan ama ṣe Farisi, eyi ekeji ama ṣe agbowode.

11 Nigbati eyi Farisi dide, o ngbadura ninu ara rẹ̀ wi bayi pe, Ọlọrun, mo dupẹ lọwọ rẹ, nitori ti emi kò ri bi ara iyokù, awọn alọnilọwọgba, alaiṣõtọ, panṣaga, tabi emi kò tilẹ ri bi agbowode yi.

12 Emi ngbàwẹ li ẹrinmeji li ọ̀sẹ, mo nsan idamẹwa ohun gbogbo ti mo ni.

13 Ṣugbọn agbowode duro li òkere, kò tilẹ jẹ gbé oju rẹ̀ soke ọrun, ṣugbọn o lù ara rẹ̀ li owokan àiya, o wipe, Ọlọrun ṣãnu fun mi, ẹlẹṣẹ.

14 Mo wi fun nyin, ọkọnrin yi sọkalẹ si ile rẹ̀ ni idalare jù ekeji lọ: nitori ẹnikẹni ti o ba gbé ara rẹ̀ ga, on li a o rẹ̀ silẹ; ẹniti o ba si rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ on li a o gbéga.

15 Nwọn si gbé awọn ọmọ-ọwọ tọ̀ ọ wá pẹlu, ki o le fi ọwọ́ tọ́ wọn. ṣugbọn nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ ri i, nwọn mba wọn wi.

16 Ṣugbọn Jesu pè wọn sọdọ rẹ̀, o si wipe, Ẹ jẹ ki awọn ọmọ kekere wá sọdọ mi, ẹ má si ṣe da wọn lẹkun: nitori ti irú wọn ni ijọba Ọlọrun.

17 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti kò ba gbà ijọba Ọlọrun bi ọmọ kekere, kì yio wọ̀ ibẹ̀ bi o ti wù ki o ri.

18 Ijoye kan si bère lọwọ rẹ̀, wipe, Olukọni rere, kili emi o ṣe ti emi o fi jogún ìye ainipẹkun ?

19 Jesu si bi i pe, Ẽṣe ti iwọ fi npè mi li ẹni rere ? ẹni rere kan kò si, bikoṣe ẹnikan, eyini li Ọlọrun.

20 Iwọ mọ̀ ofin wọnni, Máṣe panṣaga, máṣe pania, máṣe jale, máṣe jẹri eke, bọ̀wọ fun baba on iya rẹ.

21 O si dahùn pe, Gbogbo nkan wọnyi li emi ti nkiyesi lati igba ewe mi wá.

22 Nigbati Jesu gbọ́ nkan wọnyi, o wi fun u pe, Ohun kan li o kù fun ọ: lọ ità ohun gbogbo ti o ni, ki o si pín i fun awọn talakà, iwọ o si ni iṣura li ọrun: si wá, ki o mã tọ̀ mi lẹhin.

23 Nigbati o si gbọ́ eyi, inu rẹ̀ bajẹ gidigidi: nitoriti o li ọrọ̀ pipọ.

24 Nigbati Jesu ri i pe, inu rẹ̀ bajẹ gidigidi, o ni, Yio ti ṣoro to fun awọn ti o li ọrọ̀ lati wọ̀ ijọba Ọlọrun !

25 O rọrun fun ibakasiẹ lati wọ̀ inu oju abẹrẹ, jù fun ọlọrọ̀ lati wọ̀ ijọba Ọlọrun lọ.

26 Awọn ti o si gbọ́ wipe, Njẹ tali o ha le là ?

27 O si wipe, Ohun ti o ṣoro lọdọ enia, kò ṣoro lọdọ Ọlọrun.

28 Peteru si wipe, Sawò o, awa fi gbogbo rẹ̀ silẹ, awa si tọ̀ ọ lẹhin.

29 O si wi fun wọn pe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, Kò si ẹniti o fi ilẹ, tabi baba, tabi iya, tabi arakọnrin, tabi aya, tabi ọmọ silẹ, nitori ijọba Ọlọrun,

30 Ti kì yio si ri ọ̀pọlọpọ gbà si i li aiye yi, ati li aiye ti mbọ̀ ìye ainipẹkun.

31 ¶ Nigbana li o pè awọn mejila sọdọ rẹ̀, o si wi fun wọn pe, Sawò o, awa ngòke lọ si Jerusalemu, a o si mu ohun gbogbo ṣẹ, ti a ti kọ lati ọwọ́ awọn woli wá, nitori Ọmọ-enia.

32 Nitori a o fi i le awọn Keferi lọwọ, a o fi i ṣe ẹlẹyà, a o si fi i ṣe ẹsin, a o si tutọ́ si i lara:

33 Nwọn o si nà a, nwọn o si pa a: ni ijọ kẹta yio si dide.

34 Ọkan ninu nkan wọnyi kò si yé wọn: ọ̀rọ yi si pamọ́ fun wọn, bẽni nwọn kò si mọ̀ ohun ti a wi.

35 ¶ O si ṣe, bi on ti summọ Jeriko, afọju kan joko lẹba ọ̀na o nṣagbe:

36 Nigbati o gbọ́ ti ọwọ́ enia nkọja lọ, o bère pe, kili a le mọ̀ eyi si.

37 Nwọn si wi fun u pe, Jesu ti Nasareti li o nkọja lọ.

38 O si kigbe pe, Jesu, iwọ Ọmọ Dafidi, ṣãnu fun mi.

39 Awọn ti nlọ niwaju ba a wi pe, ki o pa ẹnu rẹ̀ mọ́: ṣugbọn on si kigbe si i kunkun pe, Iwọ Ọmọ Dafidi, ṣãnu fun mi.

40 Jesu si dẹsẹ duro, o ni, ki a mu u tọ̀ on wá: nigbati o si sunmọ ọ, o bi i,

41 Wipe, Kini iwọ nfẹ ti emi iba ṣe fun ọ ? O si wipe, Oluwa, ki emi ki o le riran.

42 Jesu si wi fun u pe, Riran: igbagbọ́ rẹ gbà ọ là.

43 Lojukanna o si riran, o si ntọ̀ ọ lẹhin, o nyìn Ọlọrun logo: ati gbogbo enia nigbati nwọn ri i, nwọn fi iyìn fun Ọlọrun.

## ORI 19.

JESU si wọle, o si kọja larin Jeriko.

2 Sá si kiyesi i, ọkọnrin kan ti a npè ni Sakeu, ẹniti iṣe olori ninu awọn agbowode, ti si iṣe ọlọrọ̀, o wà nibẹ̀.

Digitized by Google

3 O si nfẹ Jesu lati ri li ẹniti iṣe; kò si
le ri i, nitori ihá-gaga, ati nitoriti on ṣe
enia kukuru.
4 O si sure siwaju, o gùn ori igi sika-
more kan, ki o le ri i: nitoriti yio kọja lọ
niha ibẹ̀.
5 Nigbati Jesu si de ibẹ̀, o gbé oju soke,
o si ri i, o si wi fun u pe, Sakeu, yara, ki o
si sọkalẹ; nitoriti emi o wọ̀ ni ile rẹ loni.
6 O si yara, o sọkalẹ, o si fi ayọ̀ gbà a si
ọdọ.
7 Nigbati nwọn si ri i, gbogbo wọn
nkùn, wipe, O lọ iwọ̀ lọdọ ọkọnrin ti iṣe
ẹlẹṣẹ.
8 Sakeu si dide, o si wi fun Oluwa pe,
Sawò o, Oluwa, àbọ ohun ini mi ni mo
fifun talakà; bi mo ba si fi ẹ̀sun eke gbà
ohun kan lọwọ ẹnikẹni, mo san a pada ni
mẹrinmẹrin.
9 Jesu si wi fun u pe, Loni ni igbala wọ̀
ile yi, pẹlupẹlu ọkan ninu awọn ọmọ Abra-
hamu ni iṣe.
10 Nitori Ọmọ-enia de lati wá awọn ti o
nù kiri, ati lati gbà wọn là.
11 Nigbati nwọn si ngbọ́ nkan wọnyi, o
fi ọ̀rọ kún u, o si pa owe kan, nitoriti o
sunmọ Jerusalemu, ati nitoriti nwọn nrò
pe, ijọba Ọlọrun yio hàn nisisiyi.
12 ¶ O si wipe, Ọkọnrin kan ọlọlá rè ilu
òkere lọ igbà ijọba fun ara rẹ̀, ki o si pada.
13 O si pè awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ mẹwa, o fi
mina (oṣuwọn iwuwo) mẹwa fun wọn, o si
wi fun wọn pe, Ẹ mã ṣòwo titi emi o fi de.
14 Ṣugbọn awọn ọlọ̀tọ ilu rẹ̀ korira rẹ̀,
nwọn si rán ikọ̀ tẹle e, wipe, Awa kì yio
gbà ọkọnrin yi lati jọba lori wa.
15 O si ṣe, nigbati o gbà ijọba tan, ti o
pada de, o ni, ki a pè awọn ọmọ-ọdọ wọnni
wá, ti on ti fi owo fun nitori ki o le mọ̀ iye
ère ti olukuluku fi iṣowo jẹ.
16 Nigbana li eyi ekini wá, o wipe,
Oluwa, mina rẹ jère mina mẹwa.
17 O si wi fun u pe, Ṣeun iwọ ọmọ-ọdọ
rere: nitoriti iwọ ṣe olõtọ li ohun kikini,
gbà ọlá oyè ilu mẹwa.
18 Eyi ekeji si wá, o wipe, Oluwa, mina
rẹ jère mina marun.
19 O si wi fun u pẹlu pe, Iwọ joye ilu
marun.
20 Ẹlomiran si wá, o wipe, Oluwa, wò
mina rẹ ti mbẹ li ọwọ́ mi ti a dì sinu gèle:
21 Nitoriti mo bẹ̀ru rẹ, ati itoriti iwọ ṣe
onrorò enia: iwọ ama mu eyi ti iwọ kò fi
lelẹ, iwọ a si ma ká eyi ti iwọ kò si gbìn.
22 O si dahùn wi fun u pe, Li ẹnu ara
rẹ na li emi o ti ṣe idajọ rẹ, iwọ ọmọ-ọdọ
buburu yi. Iwọ mọ̀ pe onrorò enia ni mi,
emi ama mu eyi ti emi ko fi lelẹ, emi a si
ma ká eyi ti emi ko gbìn;
23 Ẽha si ti ṣe ti iwọ ko fi owo mi sinu
ile elé, nigbati mo de emi iba si bère rẹ̀ ti
on ti elé?
24 O si wi fun awọn ti o duro leti ibẹ̀
pe, Ẹ gbà mina na lọwọ rẹ̀, ki ẹ si fi i fun
ẹniti o ni mina mẹwa.
25 (Nwọn si wi fun u pe, Oluwa, o ni
mina mẹwa.)
26 Nitori mo wi fun nyin pe, Ẹnikẹni
ti o ni, on li a o fifun; ati lọdọ ẹniti kò ni,
eyi na ti o ni on li a o gbà lọwọ rẹ̀.
27 Ṣugbọn awọn ọtá mi wọnni, ti kò fẹ
ki emi ki o jọba lori wọn, ẹ fà wọn wá
nihinyi, ki ẹnyin ki o si pa wọn niwaju mi.
28 ¶ Nigbati o wi nkan wọnyi tan, o
ṣaju, o ngòke lọ si Jerusalemu.
29 O si ṣe, nigbati o sunmọ Betfage on
Betani li òke ti a npè ni Olifi, o rán awọn
meji ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀,
30 Wipe, Ẹ lọ si iletò ti o kọju si nyin;
nigbati ẹnyin ba nwọ̀ ọ lọ, ẹnyin o ri ọmọ
kẹtẹkẹtẹ kan ti a so, ti ẹnikẹni kò gùn ri:
ẹ tú u, ki ẹ si fà a wá.
31 Bi ẹnikẹni ba bi nyin pe, Ẽṣe ti ẹnyin
fi ntú u? ki ẹnyin ki o wi fun u bayi pe,
Nitoriti Oluwa ni ifi i ṣe.
32 Awọn ti a rán si mu ọ̀na wọn pọ̀n,
nwọn si bá a gẹgẹ bi o ti wi fun wọn.
33 Bi nwọn si ti ntú ọmọ kẹtẹkẹtẹ na,
awọn oluwa rẹ̀ bi wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi
ntú kẹtẹkẹtẹ nì?
34 Nwọn si wipe, Oluwa ni ifi i ṣe.
35 Nwọn si fà a tọ̀ Jesu wá: nwọn si tẹ́
aṣọ wọn si ẹ̀hin ọmọ kẹtẹkẹtẹ na, nwọn si
gbé Jesu kà a.
36 Bi o si ti nlọ, nwọn tẹ́ aṣọ wọn si
ọ̀na.
37 Bi o si ti sunmọ eti ibẹ̀ ni gẹrẹgẹrẹ
òke Olifi, gbogbo ijọ awọn ọmọ-ẹhin rẹ
bẹrẹ si iyọ̀, ati si ifi ohùn rara yìn Ọlọrun,
nitori iṣẹ nla gbogbo ti nwọn ti ri;
38 Wipe, Olubukun li Ọba ti o mbọ̀ wá
li orukọ Oluwa: alafia li ọrun, ati ogo loke
ọrun.
39 Awọn kan ninu awọn Farisi li awujọ
si wi fun u pe, Olukọni, ba awọn ọmọ-ẹhin
rẹ wi.
40 O si da wọn lohùn, o wi fun wọn pe,
Mo wi fun nyin, Bi awọn wọnyi ba pa ẹnu
wọn mọ́, awọn okuta yio kigbe soke.
41 ¶ Nigbati o si sunmọ etile, o ṣijuwò
ilu na, o sọkun si i lori,
42 O nwipe, Ibaṣepe iwọ mọ̀, iwọ na,



Digitized by Google

loni ọjọ rẹ, ohun ti iṣe alafia rẹ ! ṣugbọn
nisisiyi nwọn pamọ́ kuro li oju rẹ.
43 Nitori ọjọ mbọ̀ fun ọ, ti awọn ọtá rẹ
yio wà yàra ká ọ, nwọn o si yi ọ ká, nwọn
o si saga tì ọ niha gbogbo,
44 Nwọn o si wó ọ palẹ bẹrẹ, ati awọn
ọmọ rẹ ninu rẹ ; nwọn kì yio si fi okuta
kan silẹ lori ara wọn ; nitoriti iwọ ko mọ̀
ọjọ ìbẹwo rẹ.
45 O si wọ̀ inu tempili lọ, o si bẹ̀rẹ si
ilé awọn ti ntà ati awọn ti nrà ninu rẹ̀
sode ;
46 O wi fun wọn pe, A kọwe rẹ̀ pe, Ile
adura ni ile mi ; ṣugbọn ẹnyin ti sọ ọ di
ihò olè.
47 O si nkọ́ni li ọjọ gbogbo ni tempili.
Ṣugbọn awọn olori alufa, ati awọn akọwe,
ati awọn alàgba enia nwá ọ̀na ati pa a run,
48 Nwọn kò si ri bi nwọn iba ti ṣe : ni-
tori gbogbo enia ṣù mọ́ ọ lati gbọ̀rọ rẹ̀.

## ORI 20.

O SI ṣe, ni ijọ kan li ọjọ wọnni, nigbati o
nkọ́ awọn enia ni tempili ti o si nwasu
ihin-rere, awọn olori alufa, ati awọn akọwe
pẹlu awọn alàgba, dide si i,
2 Nwọn si wi fun u pe, Sọ fun wa, ọlá
kini iwọ fi nṣe nkan wọnyi ? tabi tali o fun
ọ li ọlá yi ?
3 O si dahùn o si wi fun wọn pe, Emi o
si bi nyin lẽre kan pẹlu ; ki ẹnyin ki o si
da mi lohùn.
4 Baptismu ti Johannu, li ọrun li o ti
wá, tabi lọdọ enia ?
5 Nwọn si ba ara wọn gbèro wipe, Bi
awa ba wipe, Lati ọrun wá ni ; on o wipe,
Ẽṣe ti ẹnyin kò fi gbà a gbọ́ ?
6 Ṣugbọn bi awa ba si wipe, Lọdọ enia ;
gbogbo enia ni yio sọ wa li okuta ; nitori
gbogbo wọn li a yi li ọkàn pada pe, woli ni
Johannu.
7 Nwọn si dahùn wipe, nwọn kò mọ̀
ibiti o ti wá.
8 Jesu si wi fun wọn pe, Njẹ emi kì yio
wi fun nyin li ọlá ti emi fi nṣe nkan wọnyi.
9 Nigbana li o bẹ̀rẹ si ipa owe yi fun
awọn enia pe ; Ọkọnrin kan gbìn ọgba
ajara kan, o si fi ṣe agbatọju fun awọn àgbẹ,
o si re ilu òkere nigba pipẹ.
10 Nigbati o si di akokò, o rán ọmọ-ọdọ
rẹ̀ kan si awọn àgbẹ na, ki nwọn ki o le fun
u ninu eso ọgba ajara na : ṣugbọn awọn
àgbẹ lù u, nwọn si rán a pada lọwọ ofo.
11 O si tún rán ọmọ-ọdọ miran : nwọn
si lù u pẹlu, nwọn si jẹ ẹ nìya, nwọn si rán
a pada lọwọ ofo.
12 O si tún rán ẹkẹta : nwọn si ṣá a
lọgbẹ pẹlu, nwọn si lé e jade.
13 Nigbana li oluwa ọgba ajara wipe,
Ewo li emi o ṣe ? emi o rán ọmọ mi ayanfẹ
lọ : bọya nigbati nwọn ba ri i, nwọn o bu
ọlá fun u.
14 Ṣugbọn nigbati awọn àgbẹ ri i, nwọn
ba ara wọn rò pe, Eyi li arole : ẹ wá, ẹ jẹ
ki a pa a, ki ogún rẹ̀ ki o le ṣe ti wa.
15 Bẽni nwọn si lé e si ẹhin ọgba ajara,
nwọn si pa a. Njẹ kili oluwa ọgba ajara
na yio ṣe si wọn ?
16 On o wá, yio si pa awọn àgbẹ wọnni
run, yio si fi ọgba ajara rẹ̀ ṣe agbatọju fun
awọn ẹlomiran. Nigbati nwọn si gbọ́,
nwọn ni, Ki amá ri i.
17 Nigbati o si wò wọn, o ni, Ewo ha li
eyi ti a ti kọwe pe, Okuta ti awọn ọmọle
kọ̀ silẹ, on na li o di pàtaki igun ile ?
18 Ẹnikẹni ti o ba ṣubu lù okuta na yio
fọ́ ; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ṣubu lù, a o si lọ̀ ọ
lulu.
19 ¶ Awọn olori alufa ati awọn akọwe
nwá ọna ati mu u ni wakati na ; ṣugbọn
nwọn bẹ̀ru awọn enia : nitoriti nwọn mọ̀
pe, o pa owe yi mọ wọn.
20 Nwọn si ti nṣọ ọ, nwọn rán awọn
amí, ti nwọn ṣe agalamaṣa fi ara wọn pe
olõtọ enia, ki nwọn ki o le gbá ọ̀rọ rẹ̀ mu,
ki nwọn ki o le fi i fun agbara ati fun ọlá
Bãlẹ.
21 Nwọn si bi i, wipe, Olukọni, awa mọ̀
pe, iwọ ama sọ fun ni, iwọ a si ma kọ́ni
lõtọ, bẽni iwọ ko fi oju ẹnikan pè, biko-
ṣepe iwọ nkọ́ni li ọ̀na Ọlọrun nitõtọ :
22 O tọ́ fun wa lati ma san owode fun
Kesari, tabi kò tọ́ ?
23 Ṣugbọn o kiyesi arekereke wọn, o si
wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi ndán mi wò ?
24 Ẹ fi owode kan hàn mi. Tali o ni
aworan ati akọle yi ? Nwọn si da a lohùn
pe, Ti Kesari ni.
25 O si wi fun wọn pe, Nje ẹ fi ohun ti
iṣe ti Kesari fun Kesari, ati ohun ti iṣe ti
Ọlọrun fun Ọlọrun.
26 Nwọn kò si le gbá ọ̀rọ rẹ̀ mu niwaju
awọn enia : ẹnu si yà wọn si idahùn rẹ̀,
nwọn si pa ẹnu wọn mọ́.
27 ¶ Nigbana li awọn Sadusi kan wá, ti
nwọn njiyàn pe ajinde okú kò si ; nwọn si
bi i,
28 Wipe, Olukọni, Mose kọwe fun wa
pe, Bi arakọnrin ẹnikan ba kú, li ailọmọ,
ti o li aya, ki arakọnrin rẹ̀ ki o ṣu aya rẹ̀
lopó, ki o le bímọ si ipò arakọnrin rẹ̀.
29 Njẹ awọn arakọnrin meje kan ti wà :

Digitized by Google

eyi ekini gbé aya rẹ̀ ni iyawo, o si kú li
ailọmọ.
30 Eyi ekeji si ṣu u lopó, on si kú li
ailọmọ.
31 Eyi ẹkẹta si ṣu u lopó; gẹgẹ bẽ si li
awọn mejeje pẹlu: nwọn kò si fi ọmọ silẹ,
nwọn si kú.
32 Nikẹhin gbogbo wọn eyi obirin na kú
pẹlu.
33 Njẹ li ajinde okú, aya titani yio ha
ṣe ninu wọn? nitori awọn mejeje li o sá ni
i li aya.
34 Jesu si dahùn o wi fun wọn pe,
Awọn ọmọ aiye yi a ma gbeyawo, a si ma fi
wọn funni ni iyawo:
35 Ṣugbọn awọn ti a o kà si ijogún aiye
na, ati ajinde kuro ninu okú, nwọn kì
igbeyawo, a kì isi fi wọn funni ni iyawo:
36 Nitori nwọn kò le kú mọ́ lailai; ni-
toriti nwọn ba awọn angeli dọgba; awọn
ọmọ Ọlọrun si ni nwọn, nwọn di awọn ọmọ
ajinde.
37 Niti pe a jí awọn okú dide, Mose
tikararẹ̀ si ti fihàn ni igbẹ́, nigbati o pè
Oluwa ni Ọlọrun Abrahamu, ati Ọlọrun
Isaaki, ati Ọlọrun Jakọbu.
38 Nitori on kì iṣe Ọlọrun awọn okú,
bikoṣe ti awọn alãye: nitori gbogbo enia li
o wà lãye lọdọ rẹ̀.
39 ¶ Nigbana li awọn kan ninu awọn
akọwe da a lohùn, wipe, Olukọni, iwọ wi
rere.
40 Ati lẹhin eyini, ẹnikẹni kò jẹ bi i
lẽre nkankan mọ.
41 O si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti nwọn fi
nwipe, Ọmọ Dafidi ni Kristi?
42 Dafidi tikararẹ̀ si wi ninu iwe Psalmu
pe, OLUWA wi fun Oluwa mi pe, Iwọ joko
li ọwọ́ ọtún mi,
43 Titi emi o fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti
itisẹ rẹ.
44 Njẹ bi Dafidi ba pè e li Oluwa; on
ha ti ṣe jẹ ọmọ rẹ̀?
45 ¶ O si wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ li etí
gbogbo enia pe,
46 Ẹ ma kiyesi awọn akọwe, ti nwọn fẹ
lati ma rìn li aṣọ igunwa gigùn, ti nwọn fẹ
ikí-ni li ọjà, ati ipò ọlá ninu sinagogu, ati
ipò alàgba li apejẹ àse.
47 Awọn ti o jẹ ile awọn opó run tan, ti
nwọn si ngbadura pipẹ nitori aṣehàn:
awọn na ni yio jẹbi pọju.

## ORI 21.

NIGBATI o si gbé oju soke, o ri awọn
ọlọrọ̀ nfi ẹ̀bun wọn sinu apoti iṣura.
2 O si ri talakà opó kan pẹlu, o nfi owo
idẹ wẹ́wẹ meji sinu rẹ̀.
3 O si wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin,
talakà opó yi fi si i jù gbogbo wọn lọ:
4 Nitori gbogbo awọn wọnyi fi sinu
ẹ̀bun Ọlọrun ninu ọ̀pọlọpọ ini wọn; ṣugbọn
on ninu òṣi rẹ̀ o fi gbogbo ini rẹ̀ ti o ni
sinu rẹ̀.
5 ¶ Bi awọn ẹlomiran si ti nsọ̀rọ ti tem-
pili, bi a ti fi okuta daradara ati ẹ̀bun ṣe e
li ọṣọ, o ni,
6 Ohun ti ẹnyin nri wọnyi, ọjọ mbọ̀ ti a
kì yio fi okuta kan silẹ lori ara wọn, ti a
kì yio wó lulẹ.
7 Nwọn si bère lọwọ rẹ̀, wipe, Olukọni,
nigbawo ni nkan wọnyi yio ṣẹ? ati àmi
kini yio wà, nigbati nkan wọnyi yio fi ṣẹ?
8 O si wipe, Ẹ ma kiyesi ara, ki a máṣe
tàn nyin jẹ: nitori enia pipọ yio wá li
orukọ mi, wipe, Emi ni Kristi; akokò
igbana kù si dẹdẹ: ẹ máṣe tọ̀ wọn lẹhin.
9 Sugbọn nigbati ẹnyin ba gburó ogun
ati idagiri, ẹ máṣe bẹ̀ru: nitori nkan wọnyi
ko le ṣe ki o má ṣẹ: ṣugbọn opin na kì iṣe
lojukanna.
10 Nigbanna li o wi fun wọn pe, Orilẹ-
ède yio dide si orilẹ-ède, ati ijọba si ijọba:
11 Isẹlẹ nla yio si wà ni ibi pipọ, ati
ìyan ati ajakalẹ arùn; ati idiji, ati àmi nla
lati ọrun wá.
12 Ṣugbọn ṣaju gbogbo nkan wọnyi,
nwọn o nawọ́ mu nyin, nwọn o si ṣe inuni-
bini si nyin, nwọn o fi nyin le awọn oni-
sinagogu lọwọ, ati sinu tubu, nwọn o mu
nyin lọ sọdọ awọn ọba ati ijoye nitori
orukọ mi.
13 Yio si pada di ẹrí fun nyin.
14 Ki ẹnyin ki o si pinnu rẹ̀ li ọkàn
nyin, ki ẹnyin ki o máṣe rònu ṣaju li ohùn
ti ẹnyin o da:
15 Nitoriti emi o fun nyin li ẹnu ati
ọgbọ́n, ti gbogbo awọn ọtá nyin kì yio le
sọrọ̀ òdi si, ti nwọn kì yio si le kò loju.
16 A o si fi nyin hàn lati ọdọ awọn õbi
nyin wá, ati lati ọdọ awọn arakọnrin, ati
ọdọ awọn ibatan, ati lati ọdọ awọn ọrẹ́ wá;
nwọn o si ṣe ki a pa ninu nyin.
17 A o si korira nyin lọdọ gbogbo enia
nitori orukọ mi.
18 Ṣugbọn irun ori nyin kan kì o ṣegbé.
19 Ninu sũru nyin ki ẹnyin ki o rà ọkàn
nyin.
20 Nigbati ẹnyin ba si ri ti a fi ogun yí
Jerusalemu ká, nigbana ni ki ẹnyin ki o
mọ̀ pe, isọdahoro rẹ̀ kù si dẹdẹ.
21 Nigbana ni ki awọn ti mbẹ ni Judea

ki o sá lọ sori òke ; ati awọn ti mbẹ larin
rẹ̀ ki nwọn jade kuro ; ki awọn ti o si mbẹ
ni igberiko ki o máṣe wọ̀ inu rẹ̀ lọ.
22 Nitori ọjọ wọnyi li ọjọ ẹsan, ki a le
mu ohun gbogbo ti a ti kọwe rẹ̀ tẹlẹ ṣẹ.
23 Ṣugbọn egbé ni fun awọn ti o lóyun,
ati fun awọn ti o nfi ọmú fun ọmọ mu ni
ijọ wọnni ! nitoriti ipọnju pipọ yio wà ni
ilẹ, ati ibinu si awọn enia yi.
24 Nwọn o si ma ti oju idà ṣubu, a o si
dì wọn ni igbekun lọ si orilẹ-ède gbogbo:
itẹmọlẹ si ni Jerusalemu li ẹsẹ awọn Keferi,
titi a o fi pari igba awọn Keferi.
25 ¶ Àmi yio wà li õrùn, ati li oṣupa,
ati ni irawọ ; ati li aiye lãlã orilẹ-ède, ti
on ti idãmu ; okun ati riru omi yio ma
hó ;
26 Àiya enia yio ma já fun ibẹru, ati fun
iwoye nkan wọnni ti mbọ̀ wá aiye : nitori
gbogbo agbara ọrun li a o mìtiti.
27 Nigbana ni nwọn o ri Ọmọ-enia ti
yio ma ti oju ọrun bọ̀ ti on ti agbara ati ogo
nla.
28 Nigbati nkan wọnyi si bẹ̀rẹ si iṣẹ, njẹ
ki ẹnyin ki o ma wò òke, ki ẹnyin ki o si
gbé ori nyin soke ; nitori idande nyin kù si
dẹ̀dẹ.
29 O si pa owe kan fun wọn pe ; Kiyesi
igi ọpọtọ, ati si igi gbogbo ;
30 Nigbati nwọn ba nrúwe, ẹnyin ri,
ẹnyin si mọ̀ fun ara nyin pe, igba ẹ̀run kù
fẹfẹ.
31 Gẹgẹ bẽ na li ẹnyin, nigbati ẹnyin ba
ri nkan wọnyi ti nṣẹ, ki ẹnyin ki o mọ̀ pe,
ijọba Ọlọrun kù si dẹ̀dẹ.
32 Lõtọ ni mo wi fun nyin, Iran yi kì
yio rekọja, titi a o fi mu gbogbo nkan
wọnyi ṣẹ.
33 Ọrun on aiye yio rekọja : ṣugbọn ọ̀rọ
mi kì yio rekọja.
34 ¶ Ki ẹnyin ki o si ma kiyesi ara nyin,
ki àiya nyin ki o máṣe kún fun wọ̀bia, ati
fun ọti amupara, ati fun aniyan aiye yi, ti
ọjọ na yio si fi de ba nyin lojijì.
35 Nitori bi ikẹkun ni yio de si gbogbo
awọn ti mbẹ ni gbogbo aiye.
36 Njẹ ki ẹnyin ki o si ma ṣọna, ki ẹ si
ma gbadura nigbagbogbo, ki a le kà nyin
yẹ si atilà gbogbo nkan wọnyi ti mbọ̀ wá
iṣẹ, ati lati duro niwaju Ọmọ-enia.
37 Nigba ọsán, a si ma kọ́ni ni tempili ;
nigba oru, a si ma jade lọ, o si wọ̀ lori òke
ti a npè ni Olifi.
38 Gbogbo enia si tọ̀ ọ wá ni tempili ni
kutukutu owurọ̀, lati gbọ́rọ̀ rẹ̀.

## ORI 22.

AJỌ ọdun aiwukara ti a npè ni Irekọja si
kù fẹfẹ.
2 Ati awọn olori alufa, ati awọn akọwe
nwá ọ̀na bi nwọn iba ti ṣe pa a ; nitoriti
nwọn mbẹ̀ru awọn enia.
3 ¶ Nigbana ni Satani wọ̀ inu Judasi
lọ, ti a npè ni Iskariotu, ọkan ninu awọn
mejila.
4 O si mu ọ̀na rẹ̀ pọ̀n, o lọ lati ba awọn
olori alufa ati awọn olori ẹṣọ́ mọ̀ ọ pọ̀, bi
on iba ti fi i hàn fun wọn.
5 Nwọn si yọ̀, nwọn ba a da majẹmu ati
fun u li owo.
6 O si ba wọn ṣe adehùn, o si nwá
ọ̀na ti yio fi fi i hàn fun wọn laisi ọ̀pọ
enia.
7 ¶ Nigbana li ọjọ ajọ ọdún aiwukara
pé, nigbati nwọn o pa ẹran irekọja.
8 O si rán Peteru on Johannu, wipe, Ẹ
lọ ipèse irekọja fun wa, ki awa ki o jẹ.
9 Nwọn si bi i pe, Nibo ni iwọ nfẹ ki a
pèse silẹ ?
10 O si wi fun wọn pe, Kiyesi i, nigbati
ẹnyin ba nwọ̀ ilu lọ, ọkọnrin kan ti nru iṣa
omi yio pade nyin ; ẹ ma ba a lọ si ilekile
ti o ba wọ̀.
11 Ki ẹnyin ki o si wi fun bãle ile na pe,
Olukọni wi fun ọ pe, Nibo ni gbàngan
apejẹ na gbé wà, nibiti emi o gbé jẹ irekọja
pẹlu awọn ọmọ-ẹhin mi ?
12 On o si fi gbàngan nla kan loke hàn
nyin, ti a ṣe lọṣọ : nibẹ̀ ni ki ẹnyin ki o
pèse silẹ.
13 Nwọn si lọ, nwọn si bá a gẹgẹ bi
o ti sọ fun wọn : nwọn si pèse irekọja
silẹ.
14 Nigbati o si di akokò, o joko ati awọn
aposteli mejila pẹlu rẹ̀.
15 O si wi fun wọn pe, Tinu-tinu li emi
nfẹ fi ba nyin jẹ irekọja yi, ki emi ki o to
jìya :
16 Nitori mo wi fun nyin, Emi kì yio
jẹ ninu rẹ̀ mọ́, titi a o fi pari rẹ̀ ni ijọba
Ọlọrun.
17 Nigbati o si mu ago, o sure, o ni,
Gbà eyi, ki ẹnyin ki o si pín i larin ara
nyin.
18 Nitori mo wi fun nyin, Emi kì yio
mu ninu eso ajara mọ́, titi ijọba Ọlọrun yio
fi de.
19 ¶ Nigbati o si mu akara, o sure, o
si bu u, o si fifun wọn, o wipe, Ara mi
ti a fifun nyin li eyi : ẹ mã ṣe eyi ni iranti
mi.

Digitized by Google

20 Bẹ̃ gẹgẹ pẹlu ago lẹhin onjẹ alẹ, o
wipe, Ago yi ni majẹmu titun li ẹ̀jẹ mi, ti
a ta silẹ fun nyin.
21 ¶ Ṣugbọn ki ẹnyin ki o kiyesi i, ọwọ́
ẹniti o fi mi hàn, o pẹlu mi lori tabili.
22 Ati lõtọ Ọmọ-enia nlọ bi a ti pinnu
rẹ̀: ṣugbọn egbé ni fun ọkọnrin na lọdọ
ẹniti a gbé ti fi i hàn!
23 Nwọn si bẹ̀rẹ si ibère ninu ara wọn,
li ẹniti iṣe ninu wọn, ti o jẹ ṣe nkan yi.
24 ¶ Ijà kan si mbẹ larin wọn, li ẹniti
yio ṣe olori ninu wọn.
25 O si wi fun wọn pe, Awọn ọba Keferi
ama lò ipá oluwa sori wọn: a si ma pè awọn
ti nlò ipá ọlá sori wọn ni olõre.
26 Ṣugbọn ẹnyin kì yio si ri bẹ̃: ṣu-
gbọn ẹniti o pọ̀ju lọ ninu nyin ki o jẹ bi
aburo; ati ẹniti o si ṣe ọlọlá, ki o ṣe bi
iranṣẹ.
27 Njẹ tali o pọ̀ju, ẹniti o joko tì onjẹ,
tabi ẹniti o nṣe iranṣẹ? ẹniti o joko tì onjẹ
kọ́? ṣugbọn emi mbẹ ninu nyin bi ẹniti
nṣe iranṣẹ.
28 Ẹnyin li awọn ti o ti mba mi gbé
ninu ipọnju mi.
29 Mo si yàn ijọba fun nyin, gẹgẹ bi
Baba mi ti yàn fun mi;
30 Ki ẹnyin ki o le ma jẹ, ki ẹnyin ki
o si le ma mu lori tabili mi ni ijọba mi,
ki ẹnyin ki o le joko lori itẹ́, ati ki ẹnyin
ki o le ma ṣe idajọ fun awọn ẹ̀ya Israeli
mejila.
31 ¶ Oluwa si wipe, Simoni, Simoni,
sawò o, Satani nfẹ nyin lati ni, ki o le kù
nyin bi alikama:
32 Ṣugbọn mo ti gbadura fun ọ, ki igba-
gbọ́ rẹ ki o má yẹ̀: nigbati iwọ ba si yi-
pada, mu awọn arakọnrin rẹ li ọkàn le.
33 O si wi fun u pe, Oluwa, mo mura
tan lati bá ọ lọ sinu tubu, ati si ikú.
34 O si wipe, Mo wi fun ọ, Peteru,
akukọ kì yio kọ loni, ti iwọ o fi sẹ́ mi li
ẹrinmẹta pe, iwọ kò mọ̀ mi.
35 O si wi fun wọn pe, Nigbati mo rán
nyin lọ laini asuwọn, ati birigami, ati bàta,
ọdá ohun kan da nyin bi? Nwọn si wipe,
Kò si.
36 Nigbana li o wi fun wọn pe, Ṣugbọn
nisisiyi, ẹniti o ba li asuwọn, ki o mu u,
ati birigami rẹ̀ pẹlu: ẹniti kò ba si ni idà,
ki o tà aṣọ rẹ̀, ki o si fi rà kan.
37 Nitori mo wi fun nyin pe, Eyi ti a ti
kọwe rẹ̀ kò le ṣe ki o má ṣẹ lara mi, A si kà
a mọ awọn arufin: nitori ohun wọnni nipa
ti emi o li opin.
38 Nwọn si wipe, Oluwa, sawò o, idà
meji mbẹ nihinyi. O si wi fun wọn pe, O
to.
39 ¶ Nigbati o jade, o lọ bi iṣe rẹ̀, si òke
Olifi; awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si tọ̀ ọ lẹhin.
40 Nigbati o wà nibẹ̀, o wi fun wọn pe,
Ẹ ma gbadura, ki ẹnyin ki o máṣe bọ sinu
idẹwò.
41 O si fi wọn silẹ niwọn isọ òko kan, o
si kunlẹ, o si ngbadura,
42 Wipe, Baba, bi iwọ ba fẹ, gbà ago yi
lọwọ mi: ṣugbọn ifẹ ti emi kọ́, bikoṣe tirẹ
ni ki a ṣe.
43 Angeli kan si tọ̀ ọ lati ọrun wá, o
ngbà a ni iyanju.
44 Bi o si ti wà ni iwaya-ija o ngbadura
si i kikankikan: õgùn rẹ̀ si dabi ìro ẹ̀jẹ nla,
o nkán silẹ.
45 Nigbati o si dide kuro ni ibi adura,
ti o si tọ̀ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wá, o ba wọn,
nwọn nsùn fun ikãnu,
46 O si wi fun wọn pe, Kili ẹnyin nsùn
si? ẹ dide, ẹ ma gbadura, ki ẹnyin ki o
máṣe bọ́ sinu idẹwò.
47 ¶ Bi o si ti nsọ lọwọ, kiyesi i, ọ̀pọ
enia, ati ẹniti a npè ni Judasi, ọkan ninu
awọn mejila na, o ṣaju wọn, o sunmọ Jesu
lati fi ẹnu kò o li ẹnu.
48 Ṣugbọn Jesu si wi fun u pe, Judasi,
iwọ fi ifẹnukonu fi Ọmọ-enia hàn?
49 Nigbati awọn ti o wà lọdọ rẹ̀ ri bi yio
ti jasi, nwọn bi i pe, Oluwa, ki awa ki o fi
idà ṣá wọn?
50 ¶ Ọkan ninu wọn si fi idà ṣá ọmọ-ọdọ
olori awọn alufa kan, o si ke etí ọtún rẹ̀
sọnù.
51 Ṣugbọn Jesu dahùn o wipe, Ẹ duro
to bayi na. O si fi ọwọ́ tọ́ ọ li etí, o si mu
u jinà.
52 Nigbana ni Jesu wi fun awọn olori
alufa, ati fun awọn olori ẹṣọ́ tempili ati
fun awọn alàgba, ti o wá sọdọ rẹ̀ pe, Ẹnyin
jade wá bi ẹnipe si olè, ti ẹnyin ti idà ati
ọgọ?
53 Nigbati emi fi wà pẹlu nyin ninu
tempili ni ijọ́ gbogbo, ẹnyin ko nà ọwọ́ si
mi lati mu; ṣugbọn akokò ti nyin li eyi,
ati agbara òkunkun.
54 ¶ Nigbana ni nwọn gbá a mu, nwọn
si fà a lọ, nwọn si mu u wá si ile olori
alufa. Peteru si tọ̀ ọ lẹhin li òkere.
55 Nigbati nwọn si ti dana larin gbàn-
gan, bi nwọn si ti joko pọ̀, Peteru wá o
joko larin wọn.
56 Nigbati o si ṣe, ọmọbirin kan wò o bi
o ti joko leti iná, o si tẹjumọ́ ọ, o ni,
Ọkọnrin yi pẹlu wà pẹlu rẹ̀.

Digitized by Google

57 O si sẹ́, o wipe, Obirin yi, emi ko
mọ̀ ọ.
58 O pẹ diẹ si, ẹlomiran si tun ri i, o ni,
Ati iwọ pẹlu wà ninu wọn. Peteru si wipe,
Ọkọnrin yi, Emi kọ.
59 O si di ọ̀sa wakati kan ọjọ lẹhin
eyi, ẹlomiran si tẹnumọ́ ọ, wipe, Nitõtọ
eyiyi ma wà pẹlu rẹ̀: nitori ara Galili ni
iṣe.
60 Peteru si wipe, Ọkọnrin yi, emi kò
mọ̀ eyi ti iwọ nwi. Lojukanna, bi o ti nwi
li ẹnu, akukọ kọ.
61 Oluwa si yipada, o wò Peteru. Peteru
si ranti ọ̀rọ Oluwa, bi o ti wi fun u pe,
Ki akukọ ki o to kọ, iwọ o sẹ́ mi li ẹrin-
mẹta.
62 Peteru si bọ si ode o sọkun kikorò.
63 ¶ Awọn ọkọnrin ti nwọn mu Jesu, si
fi i ṣe ẹlẹyà, nwọn lù u.
64 Nigbati nwọn si dì i loju, nwọn lù u
niwaju, nwọn mbi i pe, Sọtẹlẹ, tani nlù ọ
nì?
65 Ati nkan pipọ miran ni nwọn nfi ọ̀rọ
òdi sọ si i.
66 ¶ Nigbati ilẹ si ti mọ́, awọn alàgba
enia, ati awọn olori alufa, ati awọn akọwe
pejọ, nwọn si fà a wá si ajọ wọn, nwọn
nwipe,
67 Iwọ ni Kristi na? sọ fun wa. O si
wi fun wọn pe, Bi mo wi fun nyin, ẹnyin
ki yio gbagbọ̀:
68 Bi mo si bi nyin lẽre pẹlu, ẹnyin kì
yio da mi lohùn, bẹ̃li ẹnyin kì yio jọwọ mi
lọwọ lọ.
69 Lẹhin eyiyi li Ọmọ-enia yio joko li
ọwọ́ ọtún agbara Ọlọrun.
70 Gbogbo wọn si wipe, Iwọ ha ṣe Ọmọ
Ọlọrun bi? O si wi fun wọn pe, Ẹnyin wi
pe, emi ni.
71 Nwọn si wipe, Kili awa nwá ẹlẹri kiri
mọ́ si? Awa tikara wa sá ti gbọ́ li ẹnu ara
rẹ̀.

## ORI 23.

GBOGBO ijọ enia si dide, nwọn si fà a lọ
si ọdọ Pilatu.
2 Nwọn si bẹrẹ si ifi i sùn, wipe, Awa
ri ọkọnrin yi o nyi awọn enia li ọkàn pada,
o si nda wọn lẹkun lati san owode fun
Kesari, o nwipe on tikara-on ni Kristi ọba.
3 Pilatu si bi i lẽre, wipe, Iwọ ha li ọba
awọn Ju? O si da a lohùn wipe, Iwọ wi i.
4 Pilatu si wi fun awọn olori alufa ati
fun awọn enia pe, Emi kò ri ẹ̀ṣẹ lara ọkọn-
rin yi,
5 Nwọn si gboju si i pe, O nrulu, o
nkọ́ni ká gbogbo ilẹ awọn Ju, o bẹrẹ lati
Galili wá titi o fi de ihinyi.
6 Nigbati Pilatu gbọ́ oruko Galili, o
bère bi ọkọnrin na iṣe ara Galili.
7 Nigbati o si mọ̀ pe ara ilẹ Herodu ni,
o rán a si Herodu, ẹniti on tikararẹ̀ wà ni
Jerusalemu li akokò na.
8 ¶ Nigbati Herodu si ri Jesu, o yọ̀
gidigidi: nitoriti o ti nfẹ ẹ ri pẹ́, o sa ti
ngbọ̀ ìhin pipọ nitori rẹ̀; o si tanmã ati ri
ki iṣẹ aṣẹ diẹ ki o ti ọwọ́ rẹ̀ ṣe.
9 O si bère ọ̀rọ pipọ lọwọ rẹ̀; ṣugbọn kò
da a lohùn kanṣoṣo.
10 Ati awọn olori alufa ati awọn akọwe
duro, nwọn si nfi i sùn gidigidi.
11 Ati Herodu ti on ti awọn ọmọ-ogun
rẹ̀, nwọn kẹgan rẹ̀, nwọn si nfi i ṣẹsin,
nwọn wọ̀ ọ li aṣọ igunwà, o si rán a pada
tọ̀ Pilatu lọ.
12 Pilatu on Herodu di ọrẹ́ ni ijọ na:
nitori latijọ ọtá ara wọn ni nwọn nṣe ri.
13 ¶ Nigbati Pilatu si ti pè awọn olori
alufa ati awọn olori, ati awọn enia jọ,
14 O sọ fun wọn pe, Ẹnyin mu ọkọnrin
yi tọ̀ mi wá, bi ẹni ti o npa awọn enia li
ọkàn dà: si kiyesi i, emi wadi ẹjọ rẹ̀ ni-
waju nyin, emi kò si ri ẹ̀ṣẹ lara ọkọnrin
yi, ni gbogbo nkan wọnyi ti ẹnyin fi i sùn
si:
15 Ati Herodu pẹlu: mo sá rán nyin
tọ̀ ọ lọ; si kiyesi i, ohun kan ti o yẹ si ikú
a ko ṣe si i ti ọwọ́ rẹ̀ wá.
16 Njẹ emi o nà a, emi o jọwọ rẹ̀ lọwọ
lọ.
17 Nitori iṣe ilu wọn, kò gbọdọ ṣe aidá
ọkan silẹ fun wọn nigba ajọ irekọja.
18 Gbogbo wọn si kigbe soke lọwọ
kanna, wipe, Gbé ọkọnrin yi kuro, ki iwọ
ki o si dá Barabba silẹ fun wa:
19 Ẹniti o ti itori ọ̀tẹ ti a ṣe ni ilu, ati
itori ipania, ti a sọ sinu tubu.
20 Njẹ Pilatu nfẹ da Jesu silẹ, o si tún
sọ fun wọn.
21 Ṣugbọn nwọn tún kigbe, wipe, Kàn
a mọ agbelebu, kàn a mọ agbelebu.
22 O si tún bi wọn lẽre li ẹrinkẹta pe,
Ẽṣe, buburu kili o ṣe? emi ko ri ọ̀ran ikú
lara rẹ̀: nitorina emi o nà a, emi o si jọwọ
rẹ̀ lọwọ lọ.
23 Nwọn tilẹ kirimọ́ igbe nla, nwọn nfẹ
ki a kàn a mọ agbelebu. Ohùn ti wọn ati
ti awọn olori alufa bori tirẹ̀.
24 Pilatu si fi aṣẹ fun wọn pe, ki o ri bi
nwọn ti nfẹ.
25 O si dá ẹniti a ti itori ọ̀tẹ ati ipania

Digitized by Google

sọ sinu tubu silẹ fun wọn, ẹniti nwọn fẹ;
bẹ̃li o si fi Jesu fun ifẹ wọn.
26 Bi nwọn si ti nfà a lọ, nwọn mu
ọkọnrin kan, Simoni ara Kirene, ti o nti
igberiko bọ̀, on ni nwọn si gbé agbelebu le,
ki o ma rù u wá lẹhin Jesu.
27 ¶ Ijọ enia pipọ li o ntọ̀ ọ lẹhin, ati
awọn obirin pẹlu, ti nwọn si npohùnrere
ẹkún, ti nwọn si nṣe idarò rẹ̀.
28 Ṣugbọn Jesu, yiju pada si wọn, o
wipe, Ẹnyin ọmọbirin Jerusalemu, ẹ má
sọkun fun mi, ṣugbọn ẹ sọkun fun ara
nyin, ati fun awọn ọmọ nyin.
29 Nitori kiyesi i, ọjọ mbọ̀ li eyiti ẹnyin
o wipe, Ibukun ni fun àgan, ati fun inu ti
kò bímọ ri, ati fun ọmú ti kò funni mu
ri.
30 Nigbana ni nwọn o bẹ̀rẹ si iwi fun
òke nla pe, Wó lù wa; ati fun òke kekeke
pe, Bò wa mọlẹ.
31 Nitori bi nwọn nṣe nkan wọnyi sara
igi tutù, kili a o ṣe ni ti gbigbẹ?
32 Nwọn si mu awọn miran, arufin
meji, lọ lati pa pẹlu rẹ̀.
33 Nigbati nwọn de ibi ti a npè ni Ibi
agbari, nibẹ̀ ni nwọn gbé kàn a mọ agbe-
lebu, ati awọn arufin na, ọkan li ọwọ́ ọtún,
ati ekeji li ọwọ́ òsi.
34 ¶ Nigbana ni Jesu wipe, Baba, darijì
wọn; nitoriti nwọn kò mọ̀ ohun ti nwọn
nṣe. Nwọn si pín aṣọ rẹ̀, nwọn di ìbo rẹ̀.
35 Awọn enia si duro nworan. Ati
awọn ijoye pẹlu wọn, nwọn nyọ-sùti si i,
wipe, O gbà awọn ẹlọmiran là; ki o gbà
ara rẹ̀ là, bi iba ṣe Kristi, ayanfẹ Ọlọrun.
36 Ati awọn ọmọ-ogun pẹlu nfi i ṣe
ẹlẹyà, nwọn tọ̀ ọ wá, nwọn nfi ọti kikan
fun u,
37 Nwọn si nwipe, Bi iwọ ba ṣe Ọba
awọn Ju, gbà ara rẹ là.
38 Nwọn si kọwe akọle si igberi rẹ̀ ni
ède Hellene, ati ti Latini, ati ti Heberu,
EYIYI LI ỌBA AWỌN JU.
39 ¶ Ati ọkan ninu awọn arufin ti a
kàn mọ agbelebu pẹlu rẹ̀, o nsọ ọ̀rọ buburu
si i, wipe, Bi iwọ ba ṣe Kristi, gbà ara rẹ
ati awa là.
40 Eyi ekeji si dahùn, o mba a wi pe,
Iwọ kò bẹ̀ru Ọlọrun, ti iwọ wà ninu ẹbi
na?
41 Ati awa nitõtọ; nitori ère ti wa li
awa njẹ: ṣugbọn ọkọnrin yi kò ṣe nkan
èṣi.
42 O si wi fun Jesu pe, Oluwa, ranti
mi nigbati iwọ ba de ijọba rẹ.
43 Jesu si wi fun u pe, Lõtọ ni mo wi
fun ọ, Loni ni iwọ o wà pẹlu mi ni Para-
dise.
44 O si to ìwọn wakati kẹfa ọjọ, òkun-
kun si ṣú bò gbogbo ilẹ titi o fi di wakati
ẹkẹsan ọjọ.
45 Õrùn si ṣú òkunkun, aṣọ ikele ti
tempili si ya li agbedemeji.
46 Nigbati Jesu si kigbe li ohùn rara, o
ni, Baba, li ọwọ́ rẹ ni mo fi ẹmí mi le:
nigbati o si wi bẹ̃, o jọwọ ẹmí rẹ̀ lọwọ.
47 Nigbati balogun ọrún ri ohun ti o ṣe,
o yìn Ọlọrun logo, wipe, Dajudaju olododo
li ọkọnrin yi.
48 Ati gbogbo awọn enia ti o pejọ si
iran na, nwọn nwò ohun ti nṣe, nigbati
nwọn ba lù ara wọn li õkan àiya, nwọn a
pada.
49 Ati gbogbo awọn ojulumọ̀ rẹ̀, ati
awọn obirin ti ntọ̀ ọ lẹhin lati Galili wá,
nwọn duro li òkere, nwọn nwò nkan wọnyi.
50 ¶ Sá si kiyesi i, ọkọnrin kan ti a
'npè ni Josefu, ìgbimọ, enia rere, ati olõtọ:
51 (On na ni kò ba wọn li ohùn ni ìmọ
ati ni iṣe wọn.) Ara Arimatea, ilu kan ti
awọn Ju: ẹniti on tikararẹ̀ pẹlu nreti ijọba
Ọlọrun.
52 Ọkọnrin yi tọ̀ Pilatu lọ, o si tọrọ okú
Jesu.
53 Nigbati o si sọ̀ ọ kalẹ, o si fi aṣọ
ọgbọ àla dì i, o si tẹ́ ẹ sinu ibojì ti a wọ̀
ninu okuta, nibiti a kò ti itẹ́ ẹnikẹni si ri.
54 Ọjọ na si ṣe ọjọ ipalẹmọ: ọjọ isimi
kù si dẹ̀dẹ.
55 Ati awọn obirin pẹlu, ti nwọn bá a
ti Galili wá, ti nwọn ntọ̀ ọ lẹhin, nwọn si
kiyesi ibojì, ati bi a ti tẹ́ okú rẹ̀ si.
56 Nigbati nwọn si pada, nwọn pèse
turari gbigbẹ ati turari tutù; nwọn si
simi li ọjọ isimi gẹgẹ bi ofin.

## ORI 24.

NI ijọ kini ọ̀sẹ, ni kutukutu owurọ̀,
nwọn wá si ibi ibojì, nwọn nmu
turari wá ti nwọn ti pèse silẹ, ati awọn
miran kan pẹlu wọn.
2 Nwọn si bá, a ti yi okuta kuro li ẹnu
ibojì.
3 Nigbati nwọn wọ̀ inu rẹ̀, nwọn kò si
bá okú Jesu Oluwa.
4 O si ṣe, bi nwọn ti nṣe rọunrọun kiri
niha ibẹ̀, kiyesi i, awọn ọkọnrin meji
alaṣọ didan duro leti ọdọ wọn:
5 Nigbati ẹ̀ru mba wọn, ti nwọn si
dojubolẹ, awọn angeli na bi awọn obirin
na pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi nwá alãye ninu awọn
okú?

Digitized by Google

6 Kò si nihinyi, ṣugbọn o jinde: ki
ẹnyin ki o ranti bi o ti wi fun nyin nigbati
o wà ni Galili.
7 Wipe, A kò le ṣaima fi Ọmọ-enia le
awọn enia ẹlẹṣẹ lọwọ, a o si kàn a mọ
agbelebu, ni ijọ kẹta yio si jinde.
8 Nwọn si ranti ọ̀rọ rẹ̀.
9 Nwọn si pada ti iboji wá, nwọn si
ròhin gbogbo nkan wọnyi fun awọn mọ-
kanla, ati fun gbogbo awọn iyokù.
10 Awọn Maria Magdalene ni, ati
Joanna, ati Maria, iya Jakọbu, ati awọn
ẹlomiran pẹlu wọn, ti nwọn ròhin nkan
wọnyi fun awọn aposteli.
11 Ọ̀rọ wọn si dabi isọkusọ fun wọn,
nwọn kò si gbà wọn gbọ́.
12 Nigbana ni Peteru dide, o sure lọ si
iboji; nigbati o si bẹ̀rẹ, o ri a fi aṣọ ọgbọ
àla lelẹ li ọ̀tọ fun ara wọn, o si pada, hà
nṣe on tikararẹ̀ si ohun ti o ṣe.
13 ¶ Si kiyesi i, awọn meji ninu wọn
nlọ ni ijọ na si iletò kan ti a npè ni Em-
mausi, ti o jina si Jerusalemu niwọn ọgọta
stadia (furlongi).
14 Nwọn mba ara wọn sọ̀rọ gbogbo nkan
wọnyi ti o ṣe aṣe-le ara wọn wọnyi.
15 O si ṣe, nigbati nwọn mba ara wọn
sọ, ti nwọn si mba ara wọn rò, Jesu tika-
rarẹ̀ sunmọ wọn, o si mba wọn rìn lọ.
16 Ṣugbọn a rú wọn li oju ki nwọn ki o
máṣe le mọ̀ ọ.
17 O si bi wọn pe, Ọ̀rọ kili ẹnyin mba
ara nyin sọ, bi ẹnyin ti nrìn, ti ẹnyin si
fajuro?
18 Ọkan ninu wọn, ti a npè ni Kleopa,
si dahùn wi fun u pe, Alejò ṣá ni iwọ ni
Jerusalemu, ti iwọ kò si mọ̀ ohun ti o ṣe
nibẹ̀ li ọjọ wọnyi?
19 O si bi wọn pe, Kini? Nwọn si wi
fun u pe, Niti Jesu ti Nasareti, ẹniti iṣe
woli, ti o pọ̀ ni iṣẹ aṣẹ ati li ọ̀rọ niwaju
Ọlọrun ati niwaju gbogbo enia:
20 Ati bi awọn olori alufa ati awọn
alàgba wa ti da a lẹbi ikú, ati bi nwọn ti
kàn a mọ agbelebu.
21 Bẽni on li awa gbẹkẹle pe, on ni iba
da Israeli ni ìde: pẹlupẹlu gbogbo nkan
wọnyi oni li o di ijọ kẹta ti nkan wọnyi
ti ṣe.
22 Awọn obirin kan pẹlu li ẹgbẹ wa, ti
nwọn lọ si iboji ni kutukutu, nwọn si wá
ida wa niji;
23 Nigbati nwọn kò si ri okú rẹ̀, nwọn
wá wipe, awọn ri iran awọn angeli ti nwọn
wipe, o wà lãye.
24 Ati awọn kan ti nwọn wà pẹlu wa lọ
si iboji, nwọn si ri i gẹgẹ bi awọn obirin ti
wi: ṣugbọn on tikararẹ̀ ni nwọn kò ri.
25 O si wi fun wọn pe, Ẹniti oyé-koyé,
ati ẹniti o yigbì li àiya lati gbà gbogbo eyi
ti awọn woli ti wi gbọ́:
26 Kò ha yẹ ki Kristi ki o jìya nkan
wọnyi ki o si wọ̀ inu ogo rẹ̀ lọ?
27 O si bẹ̀rẹ lati Mose ati gbogbo awọn
woli wá, o si tumọ̀ nkan fun wọn ninu Iwe
mimọ́ gbogbo nipa ti ara rẹ̀.
28 Nwọn si sunmọ iletò ti nwọn nlọ: o
si ṣe bi ẹnipe yio lọ si iwaju.
29 Nwọn si rọ̀ ọ, wipe, Ba wa duro:
nitori o di ọjọ alẹ, ọjọ si kọja tan. O si
wọle lọ, o ba wọn duro.
30 O si ṣe, bi o ti ba wọn joko tì onjẹ, o
mu akara, o sure si i, o si bù u, o si fifun
wọn.
31 Oju wọn si là, nwọn si mọ̀ ọ; o si di
ofo li oju wọn.
32 Nwọn si ba ara wọn sọ pe, Ọkàn wa
kò ha gbiná ninu wa, nigbati o mba wa sọ̀-
rọ li ọna, ati igbati ntumọ̀ Iwe mimọ́ fun
wa?
33 Nwọn si dide ni wakati na, nwọn
pada lọ si Jerusalemu, nwọn si ba awọn
mọkanla pejọ, ati awọn ti mbẹ lọdọ
wọn,
34 Nwipe, Oluwa jinde nitõtọ, o si ti fi
ara hàn fun Simoni.
35 Nwọn si ròhin nkan ti o ṣe li ọ̀na, ati
bi o ti di mimọ̀ fun wọn ni bibu akara.
36 ¶ Bi nwọn si ti nsọ bayi, Jesu tika-
rarẹ̀ duro li arin wọn, o si wi fun wọn pe,
Alafia fun nyin.
37 Ṣugbọn àiya fò wọn, nwọn si dijì,
nwọn ṣebi awọn rí iwin.
38 O si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ara nyin
kò lelẹ? esitiṣe ti irokuro fi nsọ ninu ọkàn
nyin?
39 Ẹ wò ọwọ́ mi ati ẹsẹ mi, pe emi ti-
karami ni: ẹ mu mi li ọwọ́, ki ẹ wò o;
nitori ti iwin kò li ẹran on egungun lara,
bi ẹnyin ti ri ti mo ni.
40 Nigbati o si wi bẽ tán, o fi ọwọ́ on
ẹsẹ rẹ̀ hàn wọn.
41 Nigbati nwọn kò si ti gbagbọ́ fun
ayọ̀, ati fun hà ti nṣe wọn, o wi fun wọn
pe, Ẹnyin ni ohunkohun jijẹ nihinyi?
42 Nwọn si fun u li ẹja bibu, ati afára
oyin diẹ.
43 Nigbati o si mu u, o jẹ loju wọn.
44 O si wi fun wọn pe, Ọ̀rọ wọnyi li emi
ti nsọ fun nyin, nigbati emi ti wà pẹlu
nyin pe, Kò le ṣe ki a má mu ohun gbo-
gbo ṣẹ, ti a ti kọ ninu ofin Mose, ati ninu

Digitized by Google

iwe awọn woli, ati ninu Psalmu, nitori
mi.
45 Nigbana li o ṣí wọn ni iyè, ki Iwe
mimọ́ ki o le yé wọn,
46 O si wi fun wọn pe, Bẹ̃li a kọwe rẹ̀,
bẹ̃li o si yẹ ki Kristi ki a jìya, ati ki o si
jinde ni ijọ kẹta kuro ninu okú:
47 Ati ki a wasu ironupiwada ati idariji
ẹ̀ṣẹ li orukọ rẹ̀, li orilẹ-ède gbogbo, bẹ̀rẹ
lati Jerusalemu lọ.
48 Ẹnyin si ni ẹlẹri nkan wọnyi.
49 ¶ Si kiyesi i, Mo rán ileri Baba mi
si nyin: ṣugbọn ẹ joko ni ilu Jerusalemu,
titi a o fi fi agbara wọ̀ nyin, lati oke ọrun wá.
50 ¶ O si mu wọn jade lọ to bi Betani,
nigbati o si gbé ọwọ́ rẹ̀ soke, o sure fun
wọn.
51 O si ṣe, bi o ti nsure fun wọn, a yà a
kuro lọdọ wọn, a si gbé e lọ si ọrun.
52 Nigbati nwọn si foribalẹ fun u, nwọn
si pada lọ si Jerusalemu pẹlu ayọ̀ pipọ:
53 Nwọn si wà ni tempili nigbagbogbo,
nwọn mbu iyìn, nwọn si nfi ibukun fun
Ọlọrun. Amin.

---

IHIN RERE

TI

# JOHANNU.

## ORI 1.

LI àtetekọṣe li Ọrọ wà, Ọrọ si wà pẹlu
Ọlọrun, Ọlọrun si li Ọrọ na.
2 On na li o si wà li àtetekọṣe pẹlu
Ọlọrun.
3 Lọwọ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo; lẹhin
rẹ̀ kò si si ohunkan ti o da ninu ohun ti
a da.
4 Ninu rẹ̀ ni ìye wà; ìye na si ni imọlẹ
araiye.
5 Imọlẹ na si nmọlẹ ninu òkunkun;
òkunkun na kò si mọ̀ ọ.
6 ¶ Ọkọnrin kan wà ti a rán lati ọdọ
Ọlọrun wá, orukọ ẹniti ijẹ Johannu.
7 On na li a si rán fun ẹri, ki o le ṣe
ẹlẹri fun Imọlẹ na, ki gbogbo enia ki o le
gbagbọ́ nipasẹ rẹ̀.
8 On kì iṣe Imọlẹ na, ṣugbọn a rán a wá
lati ṣe ẹlẹri fun Imọlẹ na.
9 Eyi li ododo Imọlẹ, ti nmọlẹ fun gbo-
gbo enia ti o wá si aiye.
10 On si wà li aiye, nipasẹ rẹ̀ li a si ti
da aiye, aiye kò si mọ̀ ọ.
11 O tọ̀ awọn ará tirẹ̀ wá, awọn ará tirẹ̀
kò si gbà a.
12 Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li
o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani
awọn na ti o gbà orukọ rẹ̀ gbọ́:
13 Awọn ẹniti a bí, kì iṣe nipa ti ẹ̀jẹ,
tabi nipa ti ifẹ ara, bẹ̃ni kì iṣe nipa ifẹ ti
enia, bikoṣe nipa ifẹ ti Ọlọrun.
14 A si sọ Ọrọ na di ara, on si mba wa
gbé, (awa si nwò ogo rẹ̀, ogo ti o dabi ti
ọmọ bíbi kanṣoṣo ti Baba), ti o kún fun
ore-ọfẹ ati otitọ.
15 ¶ Johannu si njẹri fun u, o si nkigbe,
wipe, Eyi ni, nipasẹ ẹniti mo wipe, Ẹniti
mbọ̀ lẹhin mi, o pọ̀ju mi lọ: nitori o wà
ṣiwaju mi.
16 Ati ninu ẹkún rẹ̀ ni gbogbo wa si ti
gbà, ati ore-ọfẹ kún ore-ọfẹ.
17 Nitoripe nipasẹ Mose li a ti fi ofin
funni, ṣugbọn ore-ọfẹ ati otitọ tipasẹ Jesu
Kristi wá.
18 Ko si ẹniti o ri Ọlọrun nigba kan ri;
ṣugbọn ọmọ bíbi kanṣoṣo, ti mbẹ li õkan
àiya Baba, on na li o fi i hàn.
19 ¶ Eyi si li ẹrí Johannu, nigbati awọn
Ju rán awọn alufã ati Lefite lati Jerusalemu
wá lati bi i lẽre wipe, Tani iwọ ṣe?
20 On si jẹwọ, kò si sẹ́; ṣugbọn ò jẹwọ
wi fun wọn pe, Emi kì iṣe Kristi na.
21 Nwọn si bi i wipe, Tani iwọ iṣe?
Iwọ ṣe Elijah bi? O si wipe, Emi kì iṣe
on. Iwọ ni woli nì bi? O si dahùn wipe,
Bẹ̃kọ.
22 Nitorina nwọn wi fun u pe, Tani iwọ
iṣe? ki awa ki o le fi èsi fun awọn ti o rán
wá. Kili o wi niti iwọ tikararẹ?



Digitized by Google

23 O wipe, Emi li Ohùn ẹni ti nkigbe ni
ijù, Ẹ ṣe ki ọ̀na Oluwa tọ́, gẹgẹ bi woli
Isaiah ti wi.
24 Awọn ti a rán si jẹ awọn ẹgbẹ Farisi.
25 Nwọn si bi i lẽre, nwọn wi fun u pe,
Ẽha ti ṣe ti iwọ fi mbaptisi, bi iwọ kì ba ṣe
Kristi na, tabi Elijah, tabi woli nì?
26 Johannu si da wọn lohùn, wipe, Emi
nfi omi baptisi: ṣugbọn ọkan duro larin
nyin, ẹniti ẹnyin kò mọ̀;
27 On na li ẹniti mbọ̀ lẹhin mi, ti o
pọ̀ju mi lọ, okùn bàta ẹsẹ ẹniti emi kò yẹ
lati tú.
28 Nkan wọnyi li a ṣe ni Betabara loke
odò Jordani, nibiti Johannu gbé mbaptisi
wọn.
29 ¶ Ni ijọ keji Johannu ri Jesu mbọ̀ wá
sọdọ rẹ̀; o wipe, Wò, Ọdọ-agutan Ọlọrun,
ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ!
30 Eyi li ẹniti mo ti wipe, Ọkọnrin kan
mbọ̀ wá lẹhin mi, ẹniti o pọ̀ju mi lọ: nito-
riti o ti wà ṣiwaju mi.
31 Emi kò si mọ̀ ọ: ṣugbọn ki a le fi i
hàn fun Israeli, nitorina li emi ṣe wá, ti
mo nfi omi baptisi.
32 Johannu si jẹri, o wipe, mo ri Ẹmí
sọkalẹ lati ọrun wá gẹgẹ bi àdaba, o si bà
le ori rẹ̀.
33 Emi kò si mọ̀ ọ: ṣugbọn ẹniti o rán
mi wá, lati ma fi omi baptisi, on na li o wi
fun mi pe, Lori ẹniti iwọ ba ri, ti Ẹmí
sọkalẹ si, ti o si bà le e, on na li ẹniti nfi
Ẹmí Mimọ́ baptisi.
34 Emi si ti ri i, emi si njẹri pe, Eyi li
Ọmọ Ọlọrun.
35 ¶ Ni ijọ keji lẹhin igbati Johannu
tún duro, ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ meji;
36 O si nwò bi Jesu ti nrìn, o wipe, Wò
Ọdọ-agutan Ọlọrun!
37 Awọn ọmọ-ẹhin meji na si gbọ́ nigba-
ti o wi, nwọn si tọ̀ Jesu lẹhin.
38 Nigbana ni Jesu yipada, o ri nwọn
ntọ̀ ọ lẹhin, o si wi fun wọn pe, Kili ẹnyin
nwá? Nwọn wi fun u pe, Rabbi, (itumọ̀
eyi ti ijẹ Olukọni,) nibo ni iwọ ngbé?
39 O si wi fun wọn pe, Ẹ wá wò o.
Nwọn si wá, nwọn ri ibi ti o ngbé, nwọn si
ba a joko ni ijọ na: nitoriti o to ìwọn wa-
kati kẹwa ọjọ.
40 Ọkan ninu awọn meji ti o gbọ́ nigbati
Johannu wi, ti o si tọ̀ Jesu lẹhin, ni Ande-
ru, arakọnrin Simoni Peteru.
41 On tète ri Simoni arakọnrin on tika-
rarẹ̀, o si wi fun u pe, Awa ti ri Messia,
itumọ̀ eyi ti ijẹ Kristi.
42 O si mu u wá sọdọ Jesu. Nigbati
Jesu si wò o, o wipe, Iwọ ni Simoni ọmọ
Jona: Kefa li a o si ma pè ọ, itumọ̀ eyi ti
ijẹ Peteru, (tabi Apata.)
43 ¶ Li ọjọ ti o tẹ̀le e, Jesu nfẹ jade lọ
si Galili, o si ri Filippi, o si wi fun u pe,
Mã tọ̀ mi lẹhin.
44 Ṣugbọn ara Betsaida ni Filippi iṣe,
ilu Anderu ati Peteru.
45 Filippi si ri Natanaeli, o si wi fun u
pe, Awa ti ri i, ẹniti Mose ninu ofin, ati
awọn woli ti kọwe rẹ̀, Jesu ara Nasareti,
ọmọ Josefu.
46 Natanaeli si wi fun u pe, Ohun rere
kan ha le ti Nasareti jade bi? Filippi wi
fun u pe, Jade wá wò o.
47 Jesu si ri Natanaeli mbọ̀ wá sọdọ rẹ̀,
o wi nipa tirẹ̀ pe, Wò o, ododo Israeli nitõ-
tọ, ninu ẹniti ẹtan kò si!
48 Natanaeli wi fun u pe, Nibo ni iwọ ti
mọ̀ mi? Jesu dahùn, o si wi fun u pe, Ki
Filippi ki o to pè ọ, nigbati iwọ wà labẹ
igi ọpọtọ, emi ti ri ọ.
49 Natanaeli dahùn, o si wi fun u pe,
Rabbi, iwọ li Ọmọ Ọlọrun; iwọ li Ọba
Israeli.
50 Jesu dahùn, o si wi fun u pe, Iwọ
gbagbọ́ nitoriti mo wi fun ọ pe, mo ti ri ọ
nigbati iwọ ti wà labẹ igi ọpọtọ? iwọ o si
ri ohun ti o pọ̀ju yi lọ.
51 O si wi fun u pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi
fun nyin, Lẹhin eyi ẹnyin o ri ọrun ṣí silẹ,
awọn angeli Ọlọrun yio si ma gòke, nwọn
o si ma sọkalẹ sori Ọmọ enia.

## ORI 2.

NI ijọ kẹta a nṣe igbeyawo kan ni Kana
ti Galili; iya Jesu si mbẹ nibẹ̀:
2 A si pè Jesu ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀
pẹlu, si ibi igbeyawo.
3 Nigbati nwọn si ṣe alaini ọti-waini,
iya Jesu wi fun u pe, Nwọn kò li ọti-waini.
4 Jesu wi fun u pe, Kini ṣe mi ṣe ọ,
obirin yi? wakati mi kò ti ide.
5 Iya rẹ̀ si wi fun awọn iranṣẹ pe, Ohun-
kohun ti o ba wi fun nyin, ẹ ṣe e.
6 Ikoko okuta omi mẹfa li a si gbé kalẹ
nibẹ̀, gẹgẹ bi iṣe ìwẹnu awọn Ju, ọkọkan
nwọn gbà to ìwọn ladugbo meji tabi mẹta.
7 Jesu wi fun wọn pe, Ẹ pọn omi kún
ikoko wọnni. Nwọn si kún wọn titi de
eti.
8 O si wi fun wọn pe, Ẹ bù u jade nisi-
siyi, ki ẹ si gbé e tọ̀ olori àse lọ. Nwọn si
gbé e lọ.
9 Nigbati olori àse si ti tọ́ omi ti a sọ di
ọti-waini wò, ti ko si mọ̀ ibi ti a gbé ti mu

Digitized by Google

u wá : (bikoṣe awọn iranṣẹ ti o pọn omi na
wá li o mọ̀ ;) olori àse pè ọkọ iyawo,
10 O si wi fun u pe, Olukuluku enia li
àkọṣe ama gbé ọti-waini rere kalẹ ; nigbati
awọn enia ba si mu yó tan, nigbani ni imu
eyi ti kò dara bayi wá : ṣugbọn iwọ pa ọti-
waini rere na mọ́ titi o fi di isisiyi.
11 Eyi li àkọṣe iṣẹ iyanu Jesu ni Kana
ti Galili, o si fi ogo rẹ̀ hàn jade ; awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ si gbà a gbọ́.
12 ¶ Lẹhin eyi, o sọkalẹ lọ si Kapernau-
mu, on ati iya rẹ̀ ati awọn arakọnrin rẹ̀, ati
awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ : nwọn kò si gbé ibẹ̀ li
ọjọ pipọ.
13 ¶ Ajọ irekọja awọn Ju sunmọ etile,
Jesu si lọ si Jerusalemu,
14 O si ri awọn ti ntà malu, ati agutan,
ati àdaba ni tempili, ati awọn onipaṣipàrọ
owo joko :
15 Nigbati o si fi okùn tẹrẹ ṣe paṣan
kan, o si lé gbogbo wọn jade kuro ninu
tempili, ati agutan ati malu ; o si dà owo
awọn onipaṣipàrọ owo nù, o si tari tabili
wọn ;
16 O si wi fun awọn ti ntà ẹiyẹle pe, Ẹ
kó nkan wọnni kuro nihin ; ẹ máṣe sọ ile
Baba mi di ile ọjà tità.
17 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si ranti pe, a ti
kọwe pe, Itara ile rẹ ti jẹ mi tan.
18 ¶ Nigbana li awọn Ju dahùn, nwọn
si wi fun u pe, Àmi kini iwọ fi hàn wa,
nitori ohun ti iwọ fi ṣe nkan wọnyi ?
19 Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Ẹ wó
tempili yi palẹ, ni ijọ mẹta Emi o si gbé
e ró.
20 Nigbana li awọn Ju wipe, Ọdún mẹ-
rindiladọta li a fi kọ́ tempili yi, on ni iwọ
o si gbé ró ni ijọ mẹta ?
21 Ṣugbọn tempili ti ara rẹ̀ li o nwi.
22 Nitorina nigbati o jinde kuro ninu
okú, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ ranti pe, o ti sọ eyi
fun wọn ; nwọn si gbà Iwe mimọ́ gbọ́, ati
ọ̀rọ ti Jesu sọ.
23 ¶ Njẹ nigbati o wà ni Jerusalemu, ni
ajọ irekọja, li ọjọ ajọ, ọ̀pọ enia gbagbọ́ li
orukọ rẹ̀, nigbati nwọn ri iṣẹ iyanu ti o ṣe.
24 Ṣugbọn Jesu kò gbé ara rẹ̀ le wọn
lọwọ, nitoriti o mọ̀ gbogbo wọn.
25 On ko si wa ki ẹnikẹni ki o jẹri enia
fun on : nitoriti on mọ̀ ohun ti mbẹ ninu
enia.

## ORI 3.

ỌKỌNRIN kan wà ninu awọn Farisi, ti
a npè ni Nikodemu, ijoye kan ninu
awọn Ju :
2 On na li o tọ̀ Jesu wá li oru, o si wi
fun u pe, Rabbi, awa mọ̀ pe olukọni otitọ
lati ọdọ Ọlọrun wá ni iwọ iṣe : nitoripe kò
si ẹniti o le ṣe iṣẹ iyanu wọnyi ti iwọ nṣe,
bikoṣepe Ọlọrun wà pẹlu rẹ̀.
3 Jesu dahùn o si wi fun u pe, Lõtọ,
lõtọ ni mo wi fun ọ, Bikoṣepe a tún enia
bí, on kì yio le ri ijọba Ọlọrun.
4 Nikodemu wi fun u pe, A o ti ṣe le
tún enia bí, nigbati o di agbalagba tan ? o
si le tún wọ̀ inu iya rẹ̀ lọ nigba keji, ki a si
tún u bí ?
5 Jesu dahùn wipe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi
fun ọ, Bikoṣepe a tún enia bí nipa omi, ati
nipa Ẹmí, on kì yio le wọ̀ ijọba Ọlọrun.
6 Eyiti a bí nipa ti ara, ara ni ; eyiti a si
bí nipa ti Ẹmí, ẹmí ni.
7 Ki ẹnu ki o máṣe yà ọ, nitori eyiti
mo wi fun ọ pe, A kò le ṣe alai tún nyin
bí.
8 Afẹfẹ nfẹ si ibi ti o gbé wù u, iwọ si
ngbọ́ iró rẹ̀, ṣugbọn iwọ kò mọ̀ ibi ti o gbé
ti wá, ati ibi ti o gbé nlọ ; gẹgẹ bẽni gbo-
gbo awọn ẹniti a bí nipa ti Ẹmí.
9 Nikodemu dahùn, o si wi fun u pe,
Nkan wọnyi yio ti ṣe le ri bẽ ?
10 Jesu dahùn, o si wi fun u pe, Iwọ ti
iṣe olukọni ni Israeli, kò si mọ̀ nkan
wọnyi ?
11 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun ọ, Awa nsọ
eyiti awa mọ̀, awa si njẹri eyiti awa ri ;
ẹnyin kò si gbà ẹri wa.
12 Bi mo ba sọ̀rọ ohun ti aiye yi fun
nyin, ti ẹnyin kò gbagbọ́, ẹnyin o ti ṣe
gbagbọ́ bi mo ba sọ ohun ti ọrun fun nyin ?
13 Ko si ẹnikẹni ti o gòke re ọrun, bi-
koṣe ẹniti o ti ọrun sọkalẹ wá, eyini ni
Ọmọ-enia na ti mbẹ li ọrun.
14 ¶ Bi Mose si ti gbé ejò soke li aginjù,
gẹgẹ bẽli a kò le ṣe alaigbé Ọmọ-enia soke
pẹlu :
15 Pe ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́, ki o
má ba ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ti kò
nipẹkun.
16 ¶ Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o
fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, pe ẹnikẹni ti
o ba gbà a gbọ́ kì yio ṣegbé, ṣugbọn yio ni
iye ti kò nipẹkun.
17 Nitori Ọlọrun kò rán Ọmọ rẹ̀ si aiye
lati da araiye lẹbi ; ṣugbọn ki a le ti ipasẹ
rẹ̀ gbà araiye là.
18 ¶ Ẹnikẹni ti o ba gbá a gbọ́, a kì yio
da a lẹbi ; ṣugbọn a ti da ẹniti kò gbà a
gbọ́ lẹbi na, nitoriti kò gbà orukọ Ọmọ
bíbi kanṣoṣo ti Ọlọrun gbọ́.
19 Eyi si li ẹbi pe, imọlẹ wá si aiye,

Digitized by Google

awọn araiye si fẹ òkunkun jù imọlẹ lọ, ni-
toriti iṣẹ wọn buru.
20 Nitori ẹnikẹni ti o ba ṣe buburu ni
ikorira imọlẹ, bẽni kò si jẹ wá si ibi imọlẹ,
ki a máṣe ba iṣẹ rẹ wi.
21 Ṣugbọn ẹniti o ba ṣe otitọ ni iwá si
imọlẹ, ki iṣẹ rẹ ki o le fi ara hàn pe, a ṣe
wọn nipa ti Ọlọrun.
22 ¶ Lẹhin nkan wọnyi ni Jesu pẹlu
awọn ọmọ-ẹhin rẹ wá si ilẹ Judea; nibi ti
o gbé duro pẹlu wọn, ti o si baptisi.
23 Johannu pẹlu si mbaptisi ni Ainoni,
li àgbegbe Salimu, nitoriti omi pipọ wà
nibẹ: nwọn si wá, a si baptisi wọn.
24 Nitoriti a kò ti isọ Johannu sinu
tubu.
25 ¶ Nigbana ni iyàn kan wà larin
awọn ọmọ-ẹhin Johannu ati awọn Ju,
nitori ìwẹnu.
26 Nwọn si tọ̀ Johannu wá, nwọn si wi
fun u pe, Rabbi, ẹniti o ti wà pẹlu rẹ loke
odò Jordani, ẹniti iwọ si jẹri si, kiyesi i,
on na ni mbaptisi, gbogbo enia si ntọ̀ ọ
wá.
27 Johannu dahùn o si wipe, Enia ki
iri nkankan gbà, bikoṣepe a ba ti fifun u
lati ọrun wá.
28 Ẹnyin tikara nyin jẹri mi, ti mo
wipe, Emi kì iṣe Kristi na, ṣugbọn pe emi
li a rán ṣiwaju rẹ.
29 Ẹniti o ni iyawo ni iṣe ọkọ iyawo;
ṣugbọn ọrẹ́ ọkọ iyawo li ẹniti o duro lọdọ
rẹ ti o si ngbohùn rẹ, o nyọ̀ gidigidi nitori
ohùn ọkọ iyawo; njẹ ayọ̀ mi nisisiyi di
kíkun.
30 On kò le ṣaima pọsi i, ṣugbọn emi kò
le ṣaima rẹhin.
31 Ẹniti o ti oke sọkalẹ wá pọ̀ju gbogbo
wọn lọ: ẹniti o ti inu erupẹ̀ wá elerupẹ̀ ni,
on a si ma sọ̀rọ ohun ti erupẹ̀: ẹniti o ti
ọrun sọkalẹ wá pọ̀ju gbogbo wọn lọ.
32 Eyiti o ri ti o si gbọ́, on li o njẹri
fun; kò si si ẹniti o gbà ẹrí rẹ.
33 Ẹniti o gbà ẹrí rẹ si njẹri si i pe,
otitọ li Ọlọrun.
34 Nitori ẹniti Ọlọrun rán si nsọ ọ̀rọ
Ọlọrun: nitoriti Ọlọrun kò fi Ẹmí fun u
nipa oṣuwọn.
35 Baba fẹ Ọmọ, o si ti fi ohun gbogbo
le e lọwọ.
36 Ẹniti o ba gbà Ọmọ gbọ́, o ni ìye
ainipẹkun: ẹniti kò si gbà Ọmọ gbọ́, kì
yio si ri ìye; ṣugbọn ibinu Ọlọrun mbẹ
lori rẹ.

ORI 4.

NITORINA nigbati Oluwa ti mọ̀ bi awọn
Farisi ti gbọ́ pe, Jesu nṣe, ti o si
mbaptisi awọn ọmọ-ẹhin jù Johannu lọ,
2 (Ṣugbọn Jesu tikararẹ kò baptisi, biko-
ṣe awọn ọmọ-ẹhin rẹ,)
3 O fi Judea silẹ, o si tún lọ si Galili.
4 On kò si le ṣaima kọja lọ larin Samaria.
5 Nigbana li o de ilu Samaria kan, ti a
npè ni Sikari, ti o sunmọ eti ilẹ biri nì, ti
Jakọ̀bu ti fifun Josefu, ọmọ rẹ̀.
6 Kanga Jakọbu sá wà nibẹ̀. Nitorina
bi o ti rẹ Jesu tan nitori ìrin rẹ̀, bẽli o si
joko leti kanga: akokò na si jẹ ìwọn wa-
kati kẹfa ọjọ.
7 Obirin kan, ara Samaria, si wá lati fà
omi: Jesu si wi fun u pe, Fun mi mu.
8 (Nitori awọn ọmọ-ẹhin rẹ ti lọ si ilu lọ
irà onjẹ,)
9 Nigbana li obirin ara Samaria na wi
fun u pe, Eti ri ti iwọ ti iṣe Ju, fi mbère
ohun mimu lọwọ mi, emi ẹniti iṣe obirin
ara Samaria? nitoriti awọn Ju ki iba
awọn ara Samaria lò-pọ.
10 Jesu dahùn, o si wi fun u pe, Ibaṣepe
iwọ mọ̀ ẹ̀bun Ọlọrun, ati ẹniti o wi fun ọ
pe, Fun mi mu, iwọ iba si ti bère lọwọ rẹ̀,
on iba si ti fi omi ìye fun ọ.
11 Obirin na wi fun u pe, Alàgba, iwọ
kò ni nkan ti iwọ o fi fà, bẽni kanga na
jìn: nibo ni iwọ o gbé ti mu omi ìye na
wá?
12 Iwọ pọ̀ju Jakọbu baba wa lọ bi, ẹniti
o fun wa ni kanga na, ti on tikararẹ̀ mu
ninu rẹ̀, ati awọn ọmọ rẹ̀, ati ẹran rẹ̀
pẹlu?
13 Jesu dahùn, o si wi fun u pe, Ẹnikẹ-
ni ti o ba mu ninu omi yi, orùngbẹ yio si
tún gbẹ ẹ:
14 Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba mu omi ti
emi o fifun u, orùngbẹ kì yio si gbẹ ẹ mọ́
lai; ṣugbọn omi ti emi o fifun u yio jẹ omi
kanga ninu rẹ̀, ti yio ma sun titi di ìye
ainipẹkun.
15 Obirin na si wi fun u pe, Alàgba, fun
mi li omi yi, ki orùngbẹ ki o máṣe gbẹ mi,
ki emi ki o má si wá fà nihin mọ́.
16 Jesu wi fun u pe, Lọ, pè ọkọ rẹ, ki ẹ
si wá si ihinyi.
17 Obirin na dahùn, o si wi fun u pe,
Emi kò li ọkọ. Jesu wi fun u pe, Iwọ wi
rere pe, emi kò li ọkọ:
18 Nitoriti iwọ ti li ọkọ marun ri; ati
ẹniti iwọ si ni nisisiyi kì iṣe ọkọ rẹ; iwọ
sọ otitọ li eyini.

Digitized by Google

19 Obirin na wi fun u pe, Alàgba, mo
woye pe, woli ni iwọ iṣe.
20 Awọn baba wa nsìn lori òke yi;
ṣugbọn ẹnyin wipe, Jerusalemu ni ibi ti
awọn enia iba gbé ma sìn.
21 Jesu wi fun u pe, Obirin yi, gbà mi
gbọ́, wakati na mbọ̀, nigbati kì yio ṣe lori
òke yi, tabi ni Jerusalemu, ti ẹnyin o ma
sìn Baba.
22 Ẹnyin nsìn, ẹnyin kò mọ̀ ohun ti
ẹnyin sìn: awa mọ̀ ohun ti awa nsìn: ni-
toripe lọwọ awọn Ju ni igbala ti wá.
23 Ṣugbọn wakati na mbọ̀, o si de tan
nisisiyi, nigbati awọn ti nsìn li otitọ yio
ma sìn Baba li ẹmí ati li otitọ: nitoripe
irú awọn ẹni bẽ̩ ni Baba nwá ki o ma sìn
on.
24 Ẹmí li Ọlọrun: awọn ẹniti nsìn i ko
le ṣe alaisìn i li ẹmí ati li otitọ.
25 Obirin na si wi fun u pe, emi mọ̀
pe Messia mbọ̀ wá, ẹniti a npè ni Kristi:
nigbati o ba de, yio sọ ohun gbogbo fun
wa.
26 Jesu wi fun u pe, Emi ẹniti mba ọ
sọ̀rọ yi ni.
27 ¶ Ninu eyi li awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ de,
ẹnu si yà wọn, nitoriti o mba obirin na sọ̀rọ:
ṣugbọn kò si ẹnikan ti o wipe, Kili iwọ
nwá? tabi, Ẽṣe ti iwọ fi mba a sọ̀rọ?
28 Nigbana li obirin na fi ladugbo rẹ̀
silẹ, o si mu ọ̀na rẹ̀ pọ̀n lọ si ilu, o si wi
fun awọn enia pe,
29 Ẹ wá wò ọkọnrin kan, ẹniti o sọ
ohun gbogbo ti mo ti ṣe ri fun mi: Kristi
na kọ́ yi?
30 Nigbana ni nwọn ti ilu jade, nwọn si
tọ̀ ọ wá.
31 ¶ Lakokò na awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ nrọ̀
ọ, wipe, Rabbi, jẹun.
32 Ṣugbọn o wi fun wọn pe, emi li onjẹ
kan lati jẹ, ti ẹnyin kò mọ̀.
33 Nitorina li awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ mbi
ara wọn lère wipe, Ẹnikan mu onjẹ fun u
wá lati jẹ bi?
34 Jesu wi fun wọn pe, Onjẹ mi ni lati
ṣe ifẹ ti ẹniti o rán mi, ati lati pari iṣẹ
rẹ̀.
35 Ẹnyin kò ha nwipe, O kù iwọn oṣù
mẹrin, nigbana ni ikorè yio de? wò o, mo
wi fun nyin, Ẹ gbé oju nyin soke, ki ẹ si
wò oko; nitoriti nwọn pọ́n fun ikorè tan
na.
36 Ati ẹniti nkore ngbà owo ọ̀ya rẹ̀, o si
nkó eso jọ si ìye ainipẹkun: ki ẹniti o fọn
irugbin ati ẹniti nkore, ki awọn mejeji ki
o le jọ ma yọ̀ pọ̀.
37 Ninu eyi ni ọ̀rọ nì fi jasi otitọ: Ẹni-
kan fọn irugbin, ẹnikeji si kore jọ.
38 Mo rán nyin lọ lati kore nibiti ẹnyin
kò gbé ṣe iṣẹ si: awọn ẹlomiran ti ṣe iṣẹ,
ẹnyin si wọ̀ inu iṣẹ wọn lọ.
39 Ọpọ awọn ara Samaria ti o wà ni ilu
na si gbà a gbọ́, nitori ọ̀rọ obirin na, ẹniti
o wipe, o sọ gbogbo ohun ti mo ti ṣe fun
mi.
40 Bẽ̩ni, nigbati awọn ara Samaria wá
sọdọ rẹ̀, nwọn bẹ̀ ẹ pe, ki o máṣai ba wọn
joko: o si gbé ibẹ̀ ni ijọ meji.
41 Awọn ọ̀pọlọpọ pẹlu si gbagbọ́ nitori
ọ̀rọ on tikararẹ̀;
42 Nwọn si wi fun obirin na pe, Awa
gbagbọ́ nisisiyi, ki iṣe nitori ọ̀rọ rẹ: nito-
riti awa tikara wa gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀, awa si mọ̀
pe, eyi ni Kristi na nitõtọ, ti iṣe Olugbala
araiye.
43 ¶ Lẹhin ijọ meji o ti ibẹ̀ kuro, o si lọ
si Galili.
44 Nitori Jesu tikararẹ̀ ti jẹri wipe, Woli
ki ini ọlá ni ilẹ on tikararẹ̀.
45 Nitorina nigbati o si de Galili, awọn
ara Galili gbà a, nitoriti nwọn ti ri ohun
gbogbo ti o ṣe ni Jerusalemu nigba ajọ;
nitori awọn tikara wọn lọ si ajọ pẹlu.
46 Bẽ̩ni Jesu si tún pada wá si Kana ti
Galili, nibiti o gbé sọ omi di ọti-waini.
Ọmọ alade kan si wà, ẹniti ara ọmọ rẹ̀ kò
da ni Kapernaumu.
47 Nigbati o si gbọ́ pe, Jesu ti Judea
jade wá si Galili, o tọ̀ ọ wá, o si mbẹ̀ ẹ, ki
o le sọkalẹ wá lati mu ọmọ rẹ̀ lara da:
nitoriti o wà li oju ikú.
48 Jesu si wi fun u pe, Bikoṣepe ẹnyin
ba ri àmi ati iṣẹ iyanu, ẹnyin kì yio gba-
gbọ́.
49 Ọmọ alade na wi fun u pe, Oluwa,
sọkalẹ wá, ki ọmọ mi ki o to ku.
50 Jesu wi fun u pe, Mã ba ọ̀na rẹ lọ;
ọmọ rẹ yè. Ọkọnrin na si gbà ọ̀rọ ti Jesu
sọ fun u gbọ́, o si dide lọ.
51 Bi o si ti nsọkalẹ lọ, awọn ọmọ-ọdọ
rẹ̀ pade rẹ̀, nwọn si wi fun u pe, ọmọ rẹ
yè.
52 Nigbana li o bère wakati ti o bẹ̀rẹ si
isàn lọwọ wọn. Nwọn si wi fun u pe,
Lana, ni wakati keje ọjọ, ni ibà na fi i
silẹ.
53 Bẽ̩ni baba na si mọ̀ pe, wakati kanna
gan ni, ninu eyi ti Jesu wi fun u pe, ọmọ
rẹ yè: on tikararẹ̀ si gbagbọ́, ati gbogbo
ile rẹ̀.
54 Eyi si ni iṣẹ iyanu keji, ti Jesu tun
ṣe nigbati o ti Judea jade wá si Galili.

Digitized by Google

## ORI 5.

LẸHIN nkan wọnyi ajọ awọn Ju kan kò; Jesu si gòke lọ si Jerusalemu.

2 Adagun omi kan si wà ni Jerusalemu, leti ọjà agutan, ti a npè ni Betesda li èdè Heberu, ti o ni iloro marun.

3 Ninu wọnyi li ọ̀pọ awọn abirùn enia gbé dubulẹ si, ti iṣe afọju, arọ, ati awọn gbigbẹ, nwọn si nduro dè mimì omi.

4 Nitori li akokò kan angeli kan ama sọkalẹ lọ sinu adagun, a si ma rú omi na: ẹnikẹni lẹhin igbati a ba ti rú omi na tan, ti o ba tète tẹsẹ bọ̀ inu rẹ̀, a si mu u lara da ṣaṣa ninu arunkarun ti o ni.

5 Ọkọnrin kan si wà nibẹ̀, ẹniti o ni ailera li ọdún mejidilogoji.

6 Nigbati Jesu ri ti o dubulẹ, ti o si mọ̀ pe, o pẹ nigbati o ti wà bẽ, o si wi fun u pe, Iwọ fẹ ki a mu ọ lara da bi?

7 Ọkọnrin abirùn na da a lohùn wipe, Oluwa, emi kò li ẹnikan, nigbati a nrú omi na, ti iba gbé mi sinu adagun: ṣugbọn bi mo si ti mbọ̀ wá, ẹlomiran a tẹsẹ bọ̀ inu rẹ̀ ṣiwaju mi.

8 Jesu wi fun u pe, Dide, gbé akete rẹ, ki o si ma rìn.

9 Lọgan a si mu ọkọnrin na lara da, o si gbé akete rẹ̀, o nrìn: ọjọ na si jẹ ọjọ isimi.

10 ¶ Nitorina awọn Ju wi fun ọkọnrin na ti a mu lara da pe, Ọjọ isimi li oni: kò tọ́ fun ọ lati gbé akete rẹ.

11 O si da wọn lohùn wipe, Ẹniti o mu mi lara da, on li o wi fun mi pe, Gbé akete rẹ, ki o si ma rìn.

12 Nigbana ni nwọn bi i lẽre wipe, Ọkọnrin wo li ẹniti o wi fun ọ pe, Gbé akete rẹ, ki o si ma rìn?

13 Ẹniti a mu lara da na kò si mọ̀ ẹniti o ṣe: nitori Jesu ti jade kuro nibẹ̀, nitori awọn enia pipọ wà nibẹ̀.

14 Nikẹhin Jesu ri i ni tempili o si wi fun u pe, Kiyesi i, a mu ọ lara da: má ṣe dẹṣẹ mọ́, ki ohun ti o buru jù yi lọ ki o máṣe ba ọ.

15 Ọkọnrin na dide lọ, o si sọ fun awọn Ju pe, Jesu li ẹniti o mu on lara da.

16 Nitorina li awọn Ju si nṣe inunibini si Jesu, nwọn si nwá ọ̀na lati pa a, nitoriti o ti ṣe nkan wọnyi li ọjọ isimi.

17 ¶ Ṣugbọn Jesu da wọn lohùn wipe, Baba mi ṣiṣẹ de ìhin, emi si ṣiṣẹ.

18 Nitorina li awọn Ju si nwá ọ̀na gidigidi lati pa a, ki iṣe nitoripe o ba ọjọ isimi jẹ nikan, ṣugbọn niti o wi pẹlu pe, Baba on li Ọlọrun, o nmu ara rẹ̀ ba Ọlọrun dọgba.

19 Nigbana ni Jesu dahùn, o si wi fun wọn pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ọmọ kò le ṣe ohunkohun fun ara rẹ̀, bikoṣe eyiti o ri ti Baba ṣe: nitori ohunkohun ti o ba ṣe, wọnyi li Ọmọ si nṣe pẹlu.

20 Nitori Baba fẹ Ọmọ, o si fi ohun gbogbo ti on tikararẹ̀ nṣe hàn a: on o si fi iṣẹ nla ti o pọ̀ ju wọnyi lọ hàn a, ki ẹnu ki o le yà nyin.

21 Nitoripe gẹgẹ bi Baba ti o njí okú dide, ti o si nsọ wọn di ãye; gẹgẹ bẹ̃li Ọmọ a si ma sọ awọn ti o fẹ di ãye pẹlu.

22 Nitoripe Baba kì iṣe idajọ ẹnikẹni, ṣugbọn o fi gbogbo idajọ le Ọmọ lọwọ:

23 Ki gbogbo enia ki o le ma fi ọlá fun Ọmọ, gẹgẹ bi nwọn ti nfi ọlá fun Baba. Ẹnikẹni ti kò ba fi ọlá fun Ọmọ, kò si fi ọlá fun Baba na ẹniti o rán a.

24 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba gbọ́ ọ̀rọ mi, ti o ba si gbà ẹniti o rán mi gbọ́, o ni ìye ti kò nipẹkun, on kì yio si bọ si idalẹbi; ṣugbọn o ré ikú kọja bọ sinu ìye.

25 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Wakati na mbọ̀, o si de tan nisisiyi, nigbati awọn okú yio gbọ́ ohùn Ọmọ Ọlọrun: awọn ti o ba si gbọ yio yè.

26 Nitoripe gẹgẹ bi Baba ti ni ìye ninu ara rẹ̀; gẹgẹ bẹ̃li o si fifun Ọmọ lati ni ìye ninu ara rẹ̀;

27 O si fun u li agbara lati ma ṣe idajọ pẹlu, nitoriti iṣe Ọmọ-enia.

28 Ki ẹnu ki o máṣe yà nyin si eyi: nitoripe wakati na mbọ̀, ninu eyiti gbogbo awọn ti o wà ni isà okú ni yio gbọ́ ohùn rẹ̀,

29 Nwọn o si jade wá; awọn ti o ṣe rere, si ajinde ìye; awọn ti o si ṣe buburu, si ajinde ẹbi.

30 Emi kò le ṣe ohunkohun nipa ti emi tikara mi: bi mo ti ngbọ́, bẹ̃li mo si ndajọ: ododo si ni idajọ mi; nitori ifẹ ti emi tikara mi kọ́ emi nwá, bikoṣe ifẹ ti Baba ti o rán mi.

31 Bi emi ba njẹri fun ara mi, ẹrí mi kì iṣe otitọ.

32 ¶ Ẹlomiran wà, ẹniti njẹri fun mi; emi si mọ̀ pe, otitọ li ẹrí na ti o jẹ fun mi.

33 Ẹnyin ranṣẹ lọ sọdọ Johannu, on si jẹri si otitọ.

34 Ṣugbọn emi kò wá ẹrí lọdọ enia: ṣugbọn nkan wọnyi li emi nsọ, ki ẹnyin ki o le là.

35 On si jẹ imọlẹ ti o ntàn, ti o si nràn:

Digitized by Google

ẹnyin si fẹ nigba kan lati ma yọ̀ ninu imọlẹ rẹ̀.

36 ¶ Ṣugbọn emi ni ẹlẹri ti o pọ̀ju ti Johannu ni lọ; nitori iṣẹ ti Baba ti fifun mi lati ṣe pari, iṣẹ na ti emi nṣe ni njẹri mi pe, Baba li o rán mi.

37 Ati Baba tikararẹ̀, ẹniti o rán mi ti jẹri mi. Ẹnyin kò ti igbọ́ ohùn rẹ̀ nigba kan ri, bẹ̃li ẹnyin kò ti iri àwọ rẹ̀.

38 Bẹ̃li ẹnyin kò si fẹ ọ̀rọ rẹ̀ lati ma gbé inu nyin: nitori ẹniti o rán, on li ẹnyin kò gbagbọ́.

39 ¶ Ẹ ma wá inu Iwe mimọ́: nitori ninu wọn li ẹnyin rò pe ẹnyin ni ìye ti kò nipẹkun; awọn si li awọn ti njẹri mi.

40 Ẹnyin kò si fẹ lati wá sọdọ mi, ki ẹnyin ki o le ni ìye.

41 Emi kò gbà ọlá lọdọ enia.

42 Ṣugbọn emi mọ̀ nyin pe, ẹnyin kò ni ifẹ Ọlọrun ninu nyin.

43 Emi wá li orukọ Baba mi, ẹnyin kò si gbà mi: bi ẹlomiran ba wá li orukọ on tikararẹ̀, on li ẹnyin o gbà.

44 Ẹnyin o ti ṣe gbagbọ́, ẹnyin ti ngbà ọlá lọdọ ara nyin, ti kò wá ọlá ti o ti ọdọ Ọlọrun wá nikan?

45 Ki ẹnyin ki o máṣe rò pe, emi o fi nyin sùn lọdọ Baba: ẹnikan wà ẹniti nfi nyin sùn, ani Mose, ẹniti ẹnyin gbẹkẹle.

46 Nitoripe ẹnyin iba gbà Mose gbọ́, ẹnyin iba si gbà mi gbọ́: nitoripe iwe mi li o kọ.

47 Ṣugbọn bi ẹnyin kò ba gbà iwe rẹ̀ gbọ́, ẹnyin o ti ṣe le gbà ọ̀rọ mi gbọ́?

## ORI 6.

LẸHIN nkan wọnyi, Jesu kọja si apakeji adagun Galili, ti iṣe adagun Tiberia.

2 Ọ̀pọ enia si tọ̀ ọ lẹhin, nitoriti nwọn ri iṣẹ iyanu rẹ̀, ti o ṣe si awọn ti ara wọn ṣe alaida.

3 Jesu si gùn ori òke lọ, nibẹ̀ li o si gbé joko pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀.

4 Ajọ irekọja, ajọ awọn Ju si sunmọ etile.

5 ¶ Nigbati Jesu si gbé oju rẹ̀ soke, ti o si ri ọ̀pọ enia wá sọdọ rẹ̀, o wi fun Filippi pe, Nibo li a o ti rà akara, ki awọn wọnyi ki o le jẹ?

6 O si sọ eyi lati dán a wò; nitoriti on tikararẹ̀ mọ̀ ohun ti on o ṣe.

7 Filippi da a lohùn pe, Igba owo idẹ akara ko to fun wọn, ti olukuluku wọn iba fi mu diẹ-diẹ.

8 Ọkan ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, Anderu, arakọnrin Simoni Peteru wi fun u pe,

9 Ọmọdekọnrin kan mbẹ nihinyi, ti o ni iṣu akara barle marun, ati ẹja kekere meji: ṣugbọn kini wọnni ninu ọ̀pọ enia wọnyi?

10 Jesu si wipe, Ẹ mu ki awọn enia na joko. Koriko pipọ si wà nibẹ̀. Bẹ̃li awọn ọkọnrin na joko, ni kikà, nwọn to ìwọn ẹgbẹdọgbọn enia.

11 Jesu si mu iṣu akara wọnni; nigbati o si ti dupẹ, o pín wọn fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si pín wọn fun awọn ti o joko; bẹ̃ gẹgẹ si li ẹja ni ìwọn bi nwọn ti nfẹ.

12 Nigbati nwọn si yó, o wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe, Ẹ kó ajẹkù ti o kù jọ, ki ohunkohun máṣe ṣegun.

13 Nitorina nwọn kó wọn jọ pọ̀, a si kún agbọ̀n mejila li ajẹkù iṣu akara barle marun, li eyi ti o ṣikù, ti o si pọ̀ju fun awọn tí o jẹ.

14 Nitorina nigbati awọn ọkọnrin na ri iṣẹ iyanu ti Jesu ṣe, nwọn wipe, Lõtọ eyi ni woli na ti mbọ̀ wá aiye.

15 ¶ Nigbati Jesu si woye pe, nwọn nfẹ wá ifi agbara mu on lọ ifi i jọba, o tún pada lọ sori òke on nikan.

16 Nigbati alẹ si lẹ, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si wọ̀ inu adagun lọ,

17 Nwọn si bọ sinu ọkọ̀, nwọn si gòke adagun si ìha Kapernaumu. Okunkun si kùn, Jesu kò si ti ide ọdọ wọn.

18 Omi adagun si nru nitori afẹfẹ nla ti nfẹ.

19 Nigbati nwọn wà ọkọ̀ to bi ìwọn stadia (furlongi) mẹdọgbọn tabi ọgbọ̀n, nwọn ri Jesu nrìnbọ loju omi adagun, o si sunmọ eti ọkọ̀; ẹ̀ru si bà wọn.

20 Ṣugbọn o wi fun wọn pe, Emi ni; ẹ má bẹ̀ru.

21 Nigbana ni nwọn si fi ayọ̀ nla gbà a sinu ọkọ̀: lojukanna ọkọ̀ si de ilẹ ibiti nwọn gbé nlọ.

22 ¶ Ni ijọ keji, nigbati awọn enia ti o wà li apakeji adagun ri pe, kò si ọkọ̀ miran nibẹ̀, bikoṣe ọkanna ninu eyiti awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wọ̀, ati pe Jesu kò ba awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wọ̀ inu ọkọ̀, ṣugbọn awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ nikan li o lọ;

23 (Ṣugbọn ọkọ̀ miran ti Tiberia wá, ti o sunmọ ibi ti nwọn gbe jẹ akara, lẹhin igbati Oluwa ti dupẹ tan:)

24 Nitorina nigbati awọn enia ri pe, Jesu kò si nibẹ̀, tabi awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, awọn pẹlu si mu ọkọ̀ lọ si Kapernaumu, nwọn nwá Jesu kiri.

25 Nigbati nwon si ri i li apakeji ada-

Digitized by Google

gun, nwọn wi fun u pe, Rabbi, nigbawo ni
iwọ wá sihinyi ?
26 Jesu da wọn lohùn o si wipe, Lõtọ,
lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnyin nwá mi
kiri, ki iṣe nitori ti ẹnyin ri iṣẹ iyanu, ṣu-
gbọn nitori ẹnyin jẹ iṣu akara wọnni, ẹnyin
si yó.
27 Ẹ máṣe lãlã fun onjẹ ti iṣegbé, ṣu-
gbọn fun onjẹ nì ti iwà titi di ìye ainipẹ-
kun, eyiti Ọmọ enia yio fifun nyin : nito-
ripe on li Ọlọrun Baba ti fi edidi dí.
28 Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Kili
awa o ha ṣe, ki a le ṣe iṣẹ Ọlọrun ?
29 Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Eyi
bayi ni iṣẹ Ọlọrun pe, ki ẹnyin ki o gbà
ẹniti o rán gbọ́.
30 Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Àmi
kini iwọ fihàn, ti awa o ri, ti a o fi gbà ọ
gbọ́ ? iṣẹ kini iwọ ṣe ?
31 Awọn baba wa jẹ manna li aginjù;
gẹgẹ bi a ti kọwe rẹ̀ pe, O fi onjẹ fun wọn
jẹ lati ọrun wá.
32 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, Lõtọ,
lõtọ ni mo wi fun nyin, kì iṣe Mose li o fi
onjẹ nì fun nyin lati ọrun wá; ṣugbọn
Baba mi li o fi onjẹ otitọ nì fun nyin lati
ọrun wá.
33 Nitoripe onjẹ Ọlọrun li ẹniti o ti ọrun
sọkalẹ wá, ti o si fi ìye fun araiye.
34 Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Oluwa,
mã fun wa li onjẹ yi titi lai.
35 Jesu wi fun wọn pe, Emi li onjẹ ìye:
ẹnikẹni ti o ba tọ̀ mi wá, ebi kì yio pa a;
ẹniti o ba si gbà mi gbọ́, ọrùngbẹ kì yio gbẹ
ẹ mọ́,
36 Ṣugbọn mo wi fun nyin pe, Ẹnyin
pẹlu ti ri mi, ẹnyin kò si gbagbọ́.
37 Gbogbo awọn ti Baba fifun mi, yio tọ̀
mi wá; ati ẹniti o ba si tọ̀ mi wá, emi kì
yio si ta a nù, bi o ti wù ki o ri.
38 Nitori emi sọkalẹ lati ọrun wá, kì iṣe
lati mã ṣe ifẹ ti emi tikarami, bikoṣe ifẹ ti
ẹniti o rán mi.
39 Eyi si ni ifẹ Baba ti o rán mi, pe
gbogbo awọn ti o fifun mi, ki emi ki o
máṣe sọ ọkan nù ninu wọn, ṣugbọn ki emi
ki o le jí i dide nikẹhin ọjọ.
40 Eyi si ni ifẹ ẹniti o rán mi, pe ẹni-
kẹni ti o ba ri Ọmọ, ti o ba si gbà a gbọ́,
ki o le ni ìye ainipẹkun: Emi o si jí i dide
nikẹhin ọjọ.
41 Nigbana ni awọn Ju kùn si i, nitoriti
o wipe, Emi ni onjẹ ti o ti ọrun sọkalẹ wá.
42 Nwọn si wipe, Kò ṣe eyi ni Jesu, ọmọ
Josefu, baba ati iya ẹniti awa mọ̀ ? etiṣe
wipe, Emi ti ọrun sọkalẹ wá ?
43 Nitorina Jesu dahùn, o si wi fun wọn
pe, Ẹ máṣe kùn ninu ara nyin.
44 Kò si ẹnikẹni ti o le wá sọdọ mi,
bikoṣepe Baba ti o rán mi fà a: Emi o si jí
i dide nikẹhin ọjọ.
45 A sá ti kọ ọ ninu iwe awọn woli pe,
A o si kọ́ gbogbo wọn lati ọdọ Ọlọrun.
Nitorina ẹnikẹni ti o ba ti gbọ́, ti a si ti ọdọ
Baba kọ́, on li o ntọ̀ mi wá.
46 Koṣepe ẹnikẹni tilẹ ri Baba nigba
kan ri, bikoṣepe ẹniti iṣe ti Ọlọrun, on li o
ti ri Baba.
47 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹni-
kẹni ti o ba gbà mi gbọ́, o ni ìye ainipẹ-
kun.
48 Emi li onjẹ ìye na.
49 Awọn baba nyin jẹ manna li aginjù,
nwọn si kù.
50 Eyi ni onjẹ ti o ti ọrun sọkalẹ wá,
ninu eyiti bi enia ba jẹ, ti kì yio kú.
51 Emi ni onjẹ ãye nì ti o ti ọrun sọkalẹ
wá: bi ẹnikẹni ba jẹ ninu onjẹ yi, yio yè
titi lailai: onjẹ na ti emi o si fifun u li ara
mi, ti emi o fi ṣe ìye fun araiye.
52 Nitorina li awọn Ju ṣe mba ara wọn
jiyàn, wipe, Ọkọnrin yi yio ti ṣe le fi ara
rẹ̀ fun wa lati jẹ ?
53 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, Lõtọ,
lõtọ ni mo wi fun nyin, Bikoṣepe ẹnyin ba
jẹ ẹran ara Ọmọ enia, ki ẹnyin si mu ẹ̀jẹ rẹ̀,
ẹnyin kò ni ìye ninu nyin.
54 Ẹnikẹni ti o ba jẹ ara mi, ti o ba si
mu ẹ̀jẹ mi, o ni ìye ti kò nipẹkun; Emi o
si jí i dide nikẹhin ọjọ.
55 Nitori ohun jijẹ li ara mi nitõtọ, ati
ohun mimu si li ẹ̀jẹ mi nitõtọ.
56 Ẹnikẹni ti o ba jẹ ara mi, ti o ba si
mu ẹ̀jẹ mi, o ngbé inu mi, emi si ngbé inu
rẹ̀.
57 Gẹgẹ bi Baba alãye ti rán mi, ti emi
si wà nipa ti Baba: gẹgẹ bẹ̃li ẹniti o jẹ mi,
yio si yè nipa mi.
58 Eyi si li onjẹ na ti o sọkalẹ lati ọrun
wá: kò dabi awọn baba nyin ti o jẹ manna,
ti nwọn si kú: ẹnikẹni ti o ba jẹ onjẹ yi yio
yè lailai.
59 Nkan wọnyi li o sọ ninu sinagogu, bi
o ti nkọni ni Kapernaumu.
60 Nitorina ọ̀pọ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, ni-
gbati nwọn gbọ́ eyi, nwọn wipe, Ọrọ ti o
ṣoro gidigidi li eyi; tani le gbọ́ ọ ?
61 Nigbati Jesu mọ̀ ninu ara rẹ̀ pe, awọn
ọmọ-ẹhin rẹ̀ nkùn si ọ̀rọ na, o wi fun wọn
pe, Eyi jẹ ikọsẹ̀ fun nyin bi ?
62 Njẹ kini, bi ẹnyin ba si ri ti Ọmọ-
enia ngòke lọ sibi ti o gbé ti wà ri ?

Digitized by Google

63 Ẹmí ni isọni di ãye; ara kò ni ère
kan; ọ̀rọ wọnni ti mo sọ fun nyin, ọ̀rọ ẹmi
ni, ọ̀rọ ìye si ni.
64 Ṣugbọn awọn kan wà ninu nyin ti kò
gbagbọ́. Nitori Jesu mọ̀ lati ìbẹrẹ wá ẹniti
nwọn iṣe ti ko gbagbọ́, ati ẹniti yio fi on
hàn.
65 O si wipe, Nitorina ni mo ṣe wi fun
nyin pe, kò si ẹnikan ti o le tọ̀ mi wá, bi-
koṣepe a fifun u lati ọdọ Baba mi wá,
66 ¶ Lati igbana lọ ọ̀pọ awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀ pada sẹhin, nwọn kò si ba a rìn mọ́.
67 Nitorina Jesu wi fun awọn mejila pe,
Ẹnyin pẹlu nfẹ lọ bi?
68 Nigbana ni Simoni Peteru dahùn
wipe, Oluwa, sọdọ tali awa o gbé lọ? iwọ
li o ni ọ̀rọ ìye ainipẹkun.
69 Awa si gbagbọ́, o si da wa loju pe,
iwọ ni Kristi, Ọmọ Ọlọrun alãye.
70 Jesu da wọn lohùn pe, Ẹnyin mejila
kọ́ mo yàn, ọkan ninu nyin kò si yà Èṣu?
71 O nwi ti Judasi Iskariotu ọmọ Simoni:
nitoripe on li ẹniti yio fi i hàn, ẹniti iṣe
ọkan ninu awọn mejila.

## ORI 7.

LẸHIN nkan wọnyi Jesu nrìn ni Galili:
nitoriti kò fẹ rìn ni Judea, nitoriti
awọn Ju nwá ọ̀na ati pa a.
2 Njẹ ajọ ipagọ awọn Ju sunmọ etile tan.
3 Nitorina awọn arakọnrin rẹ̀ wi fun
u pe, Lọ kuro nihinyi, ki o si lọ si Judea,
ki awọn ọmọ-ẹhin rẹ pẹlu ki o le ri iṣẹ ti
iwọ nṣe.
4 Nitoripe kò si ẹnikẹni ti iṣe ohun-
kohun nikọ̀kọ, on tikararẹ̀ a si ma fẹ ki a
mọ̀ on nigbangba. Bi iwọ ba nṣe nkan
wọnyi, fi ara rẹ hàn fun araiye.
5 Nitoripe awọn arakọnrin rẹ̀ pãpã kò
tilẹ gbà a gbọ́.
6 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, Akokò
ti emi kò ti ide: ṣugbọn akokò ti nyin ni
imura tan nigbagbogbo.
7 Araiye kò le korira nyin; ṣugbọn emi
li o korira, nitoriti mo jẹri si i pe, iṣẹ rẹ̀
buru.
8 Ẹ gòke lọ si ajọ yi: emi kì yio ti
igoke lọ si ajọ yi; nitoriti akokò ti emi kò
ti ide.
9 Nigbati o ti sọ ọ̀rọ wọnyi fun wọn tan,
o duro ni Galili sibẹ̀.
10 ¶ Ṣugbọn nigbati awọn arakọnrin rẹ̀
gòke lọ tan, nigbana li on si gòke lọ si ajọ
na pẹlu, kì iṣe ni gbangba, ṣugbọn bi ẹnipe
nikọ̀kọ.
11 Awọn Ju si nwá a kiri nigba ajọ,
wipe, Nibo li o wà?
12 Ìkun pipọ li o si wà larin awọn enia
nitori rẹ̀: nitori awọn kan wipe, enia rere
ni iṣe: awọn miran wipe, Bẹ̃kọ; ṣugbọn
titàn li o ntàn enia jẹ.
13 Ṣugbọn kò si ẹnikẹni ti o sọ̀rọ rẹ̀
nigbangba nitori ìbẹru awọn Ju.
14 ¶ Nigbati o di akokò arin ajọ, Jesu
gòke lọ si tempili o si nkọ́ni.
15 Ẹnu si yà awọn Ju, nwọn wipe,
Ọkọnrin-yi ti ṣe mọ̀ iwe, ẹniti ko kọ́ nkan
ri?
16 Jesu da wọn lohùn, o si wipe, Ẹkọ́
mi kì iṣe ti emi, bikoṣe ti ẹniti o rán mi.
17 Bi ẹnikẹni o ba ṣe ifẹ rẹ̀ yio si mọ̀
ẹkọ́ na, bi iba ṣe ti Ọlọrun, tabi bi mo ba
nsọ nipa ti ara mi.
18 Ẹniti nsọ̀rọ ara rẹ̀ nwá ogo ara rẹ̀:
ṣugbọn ẹniti nwá ogo ẹniti o rán a, on na
ni iṣe olitọ, kò si si aiṣododo ninu rẹ̀.
19 Mose kò ha fi ofin fun nyin, kò si
ẹnikẹni ninu nyin ti o pa ofin na mọ́? Ẽṣe
ti ẹnyin fi nwá ọ̀na lati pa mi?
20 Awọn enia dahùn nwọn si wipe, Iwọ
li ẹmi èṣu: tani nwá ọ̀na lati pa ọ?
21 Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, kìki
iṣẹ iyanu kan ni mo ṣe, ẹnu si yà gbogbo
nyin.
22 Mose fi ikọla fun nyin; (kì iṣe nitori
ti Mose, ṣugbọn nitori ti awọn baba;) nito-
rina ẹnyin a si ma kọ enia ni ilà li ọjọ
isimi.
23 Njẹ bi enia ba gbà ikọla li ọjọ isimi,
nitori ki ofin Mose ki o máṣe bajẹ; ẹnyin
ha ti ṣe mbinu si mi, nitoriti mo mu
ẹnikan lara di ṣaṣa li ọjọ isimi?
24 Ẹ máṣe idajọ nipa ode ara, ṣugbọn ẹ
mã ṣe idajọ ododo.
25 Nigbana li awọn kan ti iṣe ara Jeru-
salemu wipe, Ẹniti nwọn nwá ọ̀na ati pa
kọ́ yi?
26 Ṣugbọn kiyesi i, on fi igboiya sọ̀rọ,
nwọn kò si wi nkankan si i. Awọn olori
ha mọ̀ nitõtọ pe, eyi ni Kristi na pãpã?
27 Ṣugbọn awa mọ̀ ibi ti ọkọnrin yi gbé
ti wá: ṣugbọn nigbati Kristi ba de, kò si
ẹniti o mọ̀ ibiti o gbé ti wá.
28 Nigbana ni Jesu kigbe ni tempili bi
o ti nkọ́ni, wipe, Ẹnyin mọ̀ mi, ẹnyin si
mọ̀ ibiti mo ti wá: emi ko si wa fun ara
mi, ṣugbọn otitọ li ẹniti o rán mi, ẹniti
ẹnyin kò mọ̀.
29 Ṣugbọn emi mọ̀ ọ: nitoripe lọdọ rẹ̀
ni mo ti wá, on li o si rán mi.
30 Nigbana ni nwọn nwá ọ̀na lati mu

u: ṣugbọn kò si ẹnikẹni ti o gbé ọwọ́ le e,
nitoriti wakati rẹ̀ kò ti ide.
31 Ọ̀pọ ninu awọn enia si gbà a gbọ́,
nwọn si wipe, Nigbati Kristi ba de, yio
ha ṣe iṣẹ iyanu jù wọnyi lọ, ti ọkọnrin yi
ti ṣe?
32 ¶ Awọn Farisi gbọ́ pe, awọn enia
nkùn niti irú nkan wọnyi nitori rẹ̀; awọn
Farisi ati awọn olori alufã si rán awọn onṣẹ
lọ lati mu u.
33 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe,
Niwọn igba diẹ si i li emi wà pẹlu nyin,
emi o si lọ sọdọ ẹniti o ràn mi.
34 Ẹnyin o wá mi kiri, ẹnyin kì yio si ri
mi: ati nibiti emi wà, nibẹ̀ li ẹnyin kì yio
le wá.
35 Niorina li awọn Ju mba ara wọn ṣe
aroye wipe, Nibo ni yio gbé lọ, ti awa kì
yio fi ri i? yio ha lọ sarin awọn Hellene ti
o fọnká kiri, lati ma kọ́ awọn Hellene bi?
36 Irú ọ̀rọ kili eyi ti o sọ yi, Ẹnyin o
wá mi, ẹnyin kì yio si ri mi: ati nibiti emi
wà, nibẹ̀ li ẹnyin kì yio le wá?
37 Lọjọ ti o kẹhìn, ọjọ nla ajọ nì, Jesu
duro, o kigbe, wipe, Bi ọrùngbẹ ba ngbẹ
ẹnikẹni, ẹ jẹ ki o wá sọdọ mi, ki o wa mu.
38 Ẹnikẹni ti o ba gbà mi gbọ́, gẹgẹ bi
Iwe mimọ́ ti wi, lati inu rẹ̀ ni odò omi ìye
yio ti ma ṣàn jade wá.
39 (Ṣugbọn o sọ eyi nipa ti Ẹmí, eyiti
awọn ti o gbà a gbọ́ yio ri gbà: nitoriti a
kò ti ifi Ẹmí Mimọ́ funni; nitoriti a kò ti
iṣe Jesu logo.)
40 ¶ Nitorina ọ̀pọ awọn enia, nigbati
nwọn gbọ́ ọ̀rọ yi, wipe, Lotitọ eyi ni woli
na.
41 Awọn miran wipe, Eyi ni Kristi na.
Ṣugbọn awọn kan si wipe, Kristi yio ha ti
Galili jade wá bi?
42 Iwe mimọ́ kò ti wipe, Kristi yio ti
inu irú ọmọ Dafidi jade wá, ati lati ilu
Betlehemu, nibiti Dafidi ti wà?
43 Bẽni iyapa si wà larin awọn enia
nitori rẹ̀.
44 Awọn miran ninu wọn si fẹ lati mu
u; ṣugbọn kò si ẹnikẹni ti o gbé ọwọ́ le e.
45 ¶ Nigbana li awọn onṣẹ pada tọ̀
awọn olori alufa ati awọn Farisi wá; nwọn
si wi fun wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin kò fi mu u
wá?
46 Awọn onṣẹ dahùn wipe, Kò si ọkọn-
rin kan ti o ti isọ̀rọ bi ọkọnrin yi.
47 Nigbana ni awọn Farisi da wọn lohùn
wipe, A ha ntàn nyin jẹ pẹlu bi?
48 O si ẹnikẹni ninu awọn ijoye, tabi
awọn Farisi ti o gbà a gbọ́?
49 Ṣugbọn ọ̀pọ enia yi ti kò mọ̀ ofin, di
ẹni ifibu.
50 Nikodemu si wi fun wọn (ẹniti o tọ̀
Jesu wá loru, o jẹ ọkan ninu wọn,)
51 Pe, ofin wa a ma ṣe idajọ ẹnikẹni ki
o to gbọ̀rọ rẹ̀, ati ki o to mọ̀ ohun ti o ṣe
bi?
52 Nwọn si dahùn wi fun u pe, Iwọ
pẹlu ṣe ara Galili ndan? Wá a kiri, ki o
si wò: nitori kò si woli kan ti o ti Galili
jade wá.
53 Olukuluku si dide lọ sinu ile rẹ̀.

## ORI 8.

JESU lọ si ori òke Olifi.
2 O si tún pada wá si tempili ni kutu-
kutu owurọ̀, gbogbo enia si wá sọdọ rẹ̀; o
si joko, o nkọ́ wọn.
3 Awọn akọwe ati awọn Farisi mu obirin
kan wá sọdọ rẹ̀, ẹniti nwọn mu ninu pan-
ṣaga; nigbati nwọn si mu u duro larin,
4 Nwọn wi fun u pe, Olukọni, awa mu
obirin yi ninu panṣaga, ninu ṣiṣe e pãpã.
5 Njẹ Mose fi aṣẹ fun wa ninu ofin pe,
ki a sọ irú rẹ̀ li okuta pa: ṣugbọn iwọ ha
ti wi?
6 Eyi ni nwọn wi, nwọn ndán a wò, ki
nwọn ki o le ba fi i sùn. Ṣugbọn Jesu bẹrẹ
silẹ, o si nfi ika rẹ̀ kọwe ni ilẹ (bi ẹnipe kò
gbọ́ eyiti nwọn nwi.)
7 Ṣugbọn nigbati nwọn kò dakun ibi i
lẽre sibẹ̀, o gbé ara rẹ̀ soke, o si wi fun
wọn pe, Ẹniti o ba ṣe ailẹṣẹ ninu nyin, jẹ
ki o tètekọ sọ okuta lù u.
8 O si tún bẹrẹ silẹ o nkọwe ni ilẹ.
9 Awọn ti o si gbọ́, nigbati ọkàn awọn
tikara wọn dá wọn lẹbi ninu wọn, nwọn
jade lọ lọkọkan, bẹrẹ lati ọdọ àgba titi o
fi de ikẹhin; o si kù Jesu nikanṣoṣo, obirin
na si duro larin.
10 Nigbati Jesu gbé ara rẹ̀ soke, ti kò si
ri ẹnikan bikoṣe obiri na, o wi fun u pe,
Obirin yi, nibo li awọn olufisùn rẹ wọnni
wà? kò si ẹnikẹni ti o da ọ lẹbi?
11 O wipe, Kò si ẹnikẹni, Oluwa. Jesu
si wi fun u pe, Bẽli emi kò si da ọ lẹbi:
mã lọ, má si tún dẹṣẹ̀ mọ́.
12 ¶ Jesu si tun sọ fun wọn wipe, Emi
ni imọlẹ aiye; ẹnikẹni ti o ba tọ̀ mi lẹhin
kì yio rìn ninu òkunkun, ṣugbọn yio ni
imọlẹ ìye.
13 Nitorina awọn Farisi wi fun u pe,
Iwọ njẹri fun ara rẹ; ẹrí rẹ kì iṣe otitọ.
14 Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Bi
mo tilẹ jẹri fun ara mi, otitọ li ẹrí mi:

Digitized by Google

nitoriti mo mọ̀ ibiti emi ti wá, mo si mọ̀
ibiti emi nlọ; ṣugbọn ẹnyin kò le mọ̀ ibiti
emi ti wá, ati ibiti emi nlọ.
15 Ẹnyin nṣe idajọ nipa ti ara; emi kò
ṣe idajọ ẹnikẹni.
16 Ṣugbọn bi mo ba si ṣe idajọ, otitọ ni
idajọ mi: nitori emi ko wà emi nikan,
ṣugbọn emi ati Baba na ti o rán mi.
17 A si kọ ọ ninu ofin nyin pe, otitọ li
ẹrí enia meji.
18 Emi li ẹniti njẹri fun ara mi, ati
Baba na ti o rán mi njẹri fun mi.
19 Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Nibo
ni Baba rẹ wà? Jesu da wọn lohùn wipe,
Ẹnyin kò mọ̀ mi, ẹnyin kò si mọ̀ Baba mi:
ibaṣepe ẹnyin mọ̀ mi, ẹnyin iba si ti mọ̀
Baba mi pẹlu.
20 Ọ̀rọ wọnyi ni Jesu sọ nibi iṣura, bi o
ti nkọ́ni ni tempili: ẹnikẹni ko si gbé ọwọ́
le e; nitoriti wakati rẹ̀ ko ti ide.
21 Nigbana ni Jesu tun wi fun wọn pe,
Emi mba ọ̀na mi lọ, ẹnyin o si wá mi,
ẹnyin o si kú ninu ẹ̀ṣẹ nyin: nibiti mo gbe
lọ, ẹnyin kì o le wá.
22 Nigbana li awọn Ju wipe, On o ha pa
ara rẹ̀ bi? nitoriti o wipe, Nibiti mo gbé
lọ, ẹnyin kì ò le wá.
23 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin li o ti
isalẹ wá; Emi li o ti oke wá: ẹnyin ni iṣe
ti aiye yi; emi kì iṣe ti aiye yi.
24 Nitorina ni mo ṣe wi fun nyin pe,
ẹnyin o kú ninu ẹ̀ṣẹ nyin: nitori bi ẹnyin
kò ba gbagbọ́ pe, emi ni, ẹnyin o kú ninu
ẹ̀ṣẹ nyin.
25 Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Tani
iwọ iṣe? Jesu si wi fun wọn pe, Ani eyi
ti mo ti wi fun nyin li àtetekọṣe wá.
26 Ọ̀pọ nkan ni mo ni isọ, ti mo si ni fi
ṣe idajọ fun nyin: ṣugbọn otitọ li ẹniti o
rán mi; emi si nsọ nkan wọnni fun araiye
ti mo ti gbọ́ lati ọdọ rẹ̀ wá.
27 Kò si yé wọn pe, nipa ti Baba li o nsọ
fun wọn.
28 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe,
Nigbati ẹnyin ba gbé Ọmọ enia soke,
nigbana li ẹnyin o mọ̀ pe, emi ni, ati pe
emi kò ṣe ohunkohun fun ara mi; ṣugbọn
bi Baba mi ti kọ́ mi, emi si nsọ nkan
wọnyi.
29 Ẹniti o rán mi si mbẹ pẹlu mi: Baba
kò si jọwọ emi nikan si; nitoriti mo nṣe
nkan wọnni ti o wù u nigbagbogbo.
30 Bi o ti nsọ ọ̀rọ wọnyi, awọn enia pipọ
gbà a gbọ́.
31 Nigbana ni Jesu wi fun awọn Ju
wọnni ti o gbà a gbọ́ pe, Bi ẹnyin ba duro
ninu ọ̀rọ mi, nigbana li ẹnyin o jẹ ọmọ-
ẹhin mi nitõtọ.
32 Ẹnyin o si mọ̀ otitọ, otitọ yio sọ
nyin di omnira.
33 ¶ Nwọn si da a lohùn wipe, Irú-ọmọ
Abrahamu li awa iṣe, awa kò ṣe ẹrú fun
ẹnikẹni ri lai: iwọ ti ṣe wipe, Ẹnyin o di
omnira?
34 Jesu dahùn o si wi fun wọn pe, Lõtọ,
lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba
dẹṣẹ, on na ni ẹrú ẹ̀ṣẹ.
35 Ẹrú kì igbé ile lailai: ṣugbọn Ọmọ
ni igbe lailai.
36 Nitorina bi Ọmọ ba sọ nyin di omni-
ra, ẹnyin o di omnira nitõtọ.
37 Emi mọ̀ pe irú-ọmọ Abrahamu li
ẹnyin iṣe; ṣugbọn ẹnyin nwá ọ̀na ati pa
mi, nitoriti ọ̀rọ mi kò ri àye ninu nyin.
38 Emi nsọ eyi ti mo ti ri lọdọ Baba mi:
ẹnyin si nṣe eyi ti ẹnyin ti ri lọdọ baba
nyin.
39 Nwọn dahùn nwọn si wi fun u pe,
Abrahamu ni baba wa. Jesu wi fun wọn
pe, Ibaṣepe awọn ọmọ Abrahamu li ẹnyin
iṣe, ẹnyin iba ṣe iṣẹ Abrahamu.
40 Ṣugbọn nisisiyi ẹnyin nwá ọ̀na ati pa
mi, ẹniti o sọ otitọ fun nyin, eyi ti mo ti
gbọ́ lọdọ Ọlọrun: Abrahamu kò ṣe eyi.
41 Ẹnyin nṣe iṣẹ ti baba nyin. Nigba-
na ni nwọn wi fun u pe, A ko bí wa nipa
panṣaga: awa ni Baba kan, eyini li Ọlọ-
run.
42 Jesu wi fun wọn pe, Ibaṣepe Ọlọrun
ni iṣe Baba nyin, ẹnyin iba fẹ mi: nitoriti
mo ti ọdọ Ọlọrun dide, mo si jade wá:
bẹ̀li emi kò si wá fun ara mi, ṣugbọn on li
o rán mi.
43 Etiṣe ti ède mi kò fi yé nyin? bikoṣe
nitori ẹnyin ko le gbọ́ ọ̀rọ mi.
44 Ẹnyin li ọmọ Èṣu baba nyin nì, ifẹ-
kufẹ ti baba nyin li ẹnyin o ṣe. Apania ni
iṣe li àtetekọṣe wá, kò ti iduro ninu otitọ
ri, nitoriti kò si otitọ ninu rẹ̀. Nigbati o
ba ṣeke, o ṣe e bi nkan tirẹ̀: nitori on li
eleke, on si ni baba rẹ̀.
45 Ṣugbọn nitoriti mo sọ otitọ fun nyin,
ẹnyin kò si gbà mi gbọ́.
46 Tani ninu nyin ti o fi oyé ẹ̀ṣẹ yé mi?
Bi o ba ṣepe otitọ ni mo wi, ẽṣe ti ẹnyin
kò gbà mi gbọ́?
47 Ẹniti iṣe ti Ọlọrun, ama gbọ́ ọ̀rọ
Ọlọrun: ṣugbọn ẹnyin kò gbọ́ ọ, nitoriti
ẹnyin kì iṣe ti Ọlọrun.
48 Nigbana li awọn Ju dahùn, nwọn si
wi fun u pe, Awa kò wi nitõtọ pe, ara Sa-
maria ni iwọ iṣe, ati pe iwọ li ẹmi èṣu?

Digitized by Google

49 Jesu dahùn wipe, Emi kò li ẹmi èṣu;
ṣugbọn emi mbù ọlá fun Baba mi, ẹnyin si
ṣe aibọla fun mi.
50 Emi kò wá ọlá ti emi tikara mi: ẹni-
kan wà ti o nwá ti o si ndajọ.
51 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Bi ẹni-
kan ba pa ọ̀rọ mi mọ́, kì yio ri ikú lailai.
52 Nigbana li awọn Ju wi fun u pe,
Nigbayi li awa mọ̀ pe iwọ li ẹmi èṣu.
Abrahamu kú, ati awọn woli; iwọ si wipe,
Bi ẹnikan ba pa ọ̀rọ mi mọ́, kì yio tọ́ ikú
wò lailai.
53 Iwọ pọ̀ju Abrahamu baba wa lọ, ẹniti
o kú? ati awọn woli kú: tani iwọ nfi ara
rẹ pè?
54 Jesu dahùn wipe, Bi mo ba mbù ọlá
fun ara mi, asan li ọlá mi: Baba mi ni
ẹniti mbù ọlá fun mi; ẹniti ẹnyin wipe,
Ọlọrun nyin ni iṣe:
55 Ṣugbọn ẹnyin kò mọ̀ ọ; ṣugbọn emi
mọ̀ ọ; bi mo ba si wipe, emi kò mọ̀ ọ, emi
o si di eleke gẹgẹ bi ẹnyin: ṣugbọn emi
mọ̀ ọ, mo si pa ọ̀rọ rẹ̀ mọ́.
56 Baba nyin, Abrahamu, yọ̀ lati ri ọjọ
mi: o si ri i, o si yọ̀.
57 Nigbana li awọn Ju wi fun u pe,
Ọdún rẹ kò ti ito adọta, iwọ si ti ri Abra-
hamu?
58 Jesu si wi fun wọn pe, Lõtọ, lõtọ ni
mo wi fun nyin, Ki Abrahamu to wà, emi
niyi.
59 Nigbana ni nwọn gbé okuta lati sọ
lù u: ṣugbọn Jesu fi ara rẹ̀ pamọ́, o si jade
kuro ni tempili o nkọja lọ larin wọn, bẽli
o si kọja lọ.

## ORI 9.

BI Jesu si ti nkọja lọ, o ri ọkọnrin kan ti
o fọju lati igba ibí rẹ̀ wá.
2 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si bi i lẽre, wipe,
Olukọni, tani ṣẹ̀, ọkọnrin yi, tabi awọn
õbi rẹ̀, niti a bí i li afọju?
3 Jesu dahùn wipe, Kì iṣe nitori ti ọkọn-
rin yi ṣẹ̀, tabi awọn õbi rẹ̀: ṣugbọn ki a le
fi iṣẹ Ọlọrun hàn lara rẹ̀.
4 Emi kò le ṣe alaiṣe iṣẹ ẹniti o rán mi,
nigbati iṣe ọsán: oru mbọ̀ wá nigbati
ẹnikan kì o le ṣe iṣẹ.
5 Niwọn igba ti mo wà li aiye, emi ni
imọlẹ aiye.
6 Nigbati o si ti wi bẽ tan, a tutọ́ silẹ,
o si fi itọ́ na ṣe amọ̀, o si fi amọ̀ na pa oju
ọkọnrin afọju na,
7 O si wi fun u pe, Lọ, wẹ̀ ninu adagun
Siloamu, (itumọ̀ eyi ti ijẹ Rán-lọ.) Nito-
rina o gbà ọ̀na rẹ̀ lọ, o wẹ̀, o si de o nriran.
8 Njẹ awọn aladugbo ati awọn ti o ri i
nigba atijọ pe a bí i li afọju, wipe, Ẹniti o
ti njoko ṣagbe kọ́ yi?
9 Awọn ọkan wipe, On li eyi: awọn
ẹlomiran wipe, O dabi on: ṣugbọn on
wipe, Emi ni.
10 Nitorina ni nwọn wi fun u pe, Oju
rẹ ti ṣe là?
11 O dahùn o si wi fun wọn pe, Ọkọn
rin kan ti a npè ni Jesu li o ṣe amọ̀, o si fi
kùn mi loju, o si wi fun mi pe, Lọ si ada-
gun Siloamu, ki o si wẹ̀: emi si lọ, mo wẹ̀,
mo si riran.
12 Nigbana ni nwọn wi fun u pe, On na
ha dà? O wipe, emi kò mọ̀.
13 ¶ Nwọn mu ọkọnrin na, ti oju rẹ̀ fọ́
lati igba ibí rẹ̀, wá sọdọ awọn Farisi.
14 O si jẹ ọjọ isimi nigbati Jesu ṣe amọ̀
na, ti o si là a loju.
15 Nigbana li awọn Farisi pẹlu tún bi i
lẽre, bi o ti ṣe riran. O si wi fun wọn pe,
O fi amọ̀ le oju mi, emi si wẹ̀, mo si riran.
16 Nitorina awọn kan ninu awọn Farisi
wipe, Ọkọnrin yi kì iṣe ti Ọlọrun, nitoriti
kò pa ọjọ isimi mọ́. Awọn ẹlomiran wipe,
Ọkọnrin ti iṣe ẹlẹṣẹ yio ti ṣe le ṣe irú iṣẹ
iyanu wọnni? Iyapa si wà larin wọn.
17 Nwọn si tun wi fun ọkọnrin afọju na
pe, Kini iwọ wi nitori rẹ̀, nitori lilà ti o là
ọ loju? O si wipe, Woli ni iṣe.
18 Ṣugbọn awọn Ju kò gbagbọ́ nitori rẹ̀
pe, oju rẹ̀ ti fọ́ ri, ati pe o si tún riran, bi-
koṣe nigbati nwọn pè awọn õbi ọkọnrin na
ti oju rẹ̀ là.
19 Nwọn si bi wọn lẽre, wipe, Eyi li
ọmọ nyin, ẹniti ẹnyin wipe, ẹ bí i li afọju?
ẽha si ti ṣe ti o nriran nisisiyi?
20 Awọn õbi rẹ̀ da wọn lohùn wipe, Awa
mọ̀ pe ọmọ wa li eyi, ati pe a bí i li afọju:
21 Ṣugbọn ọ̀na ti o gbà ti o fi nriran,
awa kò mọ̀; tabi ẹniti o là a loju, awa kò
mọ̀: ẹniti ogbọ́njú ni iṣe; ẹ bi i lẽre: yio
wi fun ara rẹ̀.
22 Ọ̀rọ wọnyi li awọn õbi rẹ̀ sọ, nitoriti
nwọn bẹ̀ru awọn Ju: nitori awọn Ju fi
ohùn ṣọkan pe, bi ẹnikẹni ba jẹwọ pe,
Kristi ni iṣe, nwọn o mu u kuro ninu sina-
gogu.
23 Nitorina li awọn õbi rẹ̀ fi wipe, Ẹniti
ogbọ́njú ni iṣe; ẹ bi i lẽre.
24 Nigbana ni nwọn si tún pè ọkọnrin
afọju na, nwọn si wi fun u pe, Fi iyìn fun
Ọlọrun: awa mọ̀ pe ẹlẹṣẹ li ọkọnrin yi iṣe.
25 O dahùn o si wipe, Bi ẹlẹṣẹ ni iṣe, bi
bẹ̀kọ, emi kò mọ̀: ohun kan ni mo mọ̀, pe
niwọn bi oju mi ti fọ́, emi nriran nisisiyi.

Digitized by Google

26 Nigbana ni nwọn si tun bi i wipe,
Kili o ṣe fun ọ? ẽtiṣe là ọ loju?
27 O da wọn lohùn wipe, Emi ti sọ fun
nyin na, ẹnyin ko gbọ́: nitori kili ẹnyin ṣe
nfẹ tún gbọ́? ẹnyin pẹlu nfẹ ṣe ọmọ-ẹhin
rẹ̀ bi?
28 Nigbana ni nwọn si fi i ṣe ẹlẹyà, wipe,
Iwọ li ọmọ-ẹhin rẹ̀; ṣugbọn ọmọ-ẹhin Mose
li awa iṣe.
29 Awa mọ̀ pe Ọlọrun ba Mose sọ̀rọ:
ṣugbọn bi o ṣe ti eyiyi, awa kò mọ̀ ibiti o
gbé ti wá.
30 Ọkọnrin na dahùn o si wi fun wọn
pe, ohun iyanu sá li eyi, nitoriti ẹnyin kò
mọ̀ ibiti o gbé ti wá, ṣugbọn on sá ti là mi
loju.
31 Awa sá mọ̀ pe, Ọlọrun ki igbọ́ ti
ẹlẹṣẹ: ṣugbọn bi ẹnikan ba ṣe olufọkànsìn
si Ọlọrun, ti o ba si ṣe ifẹ rẹ̀, on ni igbọ́
tirẹ̀.
32 Lati igba ti aiye ti ṣẹ̀, a kò ti igbọ́
pe, ẹnikan là oju ẹniti a bí li afọju ri.
33 Ibaṣepe ọkọnrin yi kì iṣe ti Ọlọrun,
kì ba ti le ṣe ohunkohun.
34 Nwọn si dahùn wi fun u pe, Iwọ ti a
bí patapata ninu ẹ̀ṣẹ, iwọ si nkọ́ wa bi?
Nwọn si tì i sode.
35 Jesu si gbọ́ pe, nwọn ti tì i sode;
nigbati o si ri i, o bi i wipe, Iwọ gbà Ọmọ
Ọlọrun gbọ́?
36 O si dahùn wipe, Tani, Oluwa, ki
emi ki o le gbà a gbọ́?
37 Jesu si wi fun u pe, Iwọ ti ri i, on na
si ni ẹniti mba a sọ̀rọ yi.
38 O si wipe, Oluwa, mo gbagbọ́, o si
tẹriba fun u.
39 ¶ Jesu si wipe, Nitori idajọ ni mo ṣe
wá si aiye yi, ki awọn ti kò riran ri, ki o
le riran; ati ki a le sọ awọn ti o riran di
afọju.
40 Awọn ọkan ninu awọn Farisi ti o wà
lọdọ rẹ̀ gbọ́ ọ̀rọ wọnyi, nwọn wi fun u pe,
Awa pẹlu fọju bi?
41 Jesu si wi fun wọn pe, Ibaṣepe ẹnyin
fọju, ẹnyin kì ba ti li ẹ̀ṣẹ: ṣugbọn ẹnyin
wipe, Awa riran; nitorina ẹ̀ṣẹ nyin wà
sibẹ̀.

## ORI 10.

LÕTỌ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni
ti kò ba gbà ẹnu-ọ̀na wọ̀ inu agbo
agutan, ṣugbọn ti o ba gbà ibomiran gùn
oke, on na li olè ati ọlọṣà.
2 Ṣugbọn ẹniti o ba ti ẹnu-ọ̀na wọle, on
ni iṣe oluṣọ-agutan.
3 On ni oludèna ṣilẹkun fun; awọn
agutan si gbohùn rẹ̀: o si pè awọn agutan
tirẹ̀ li orukọ, o si ṣe amọ̀na wọn jade.
4 Nigbati o si mu agutan tirẹ̀ jade, o
ṣiwaju wọn, awọn agutan na si ntọ̀ ọ lẹhin:
nitoriti nwọn mọ̀ ohùn rẹ̀.
5 Nwọn kì itọ̀ alejò lẹhin, ṣugbọn nwọn
ama sá lọdọ rẹ̀: nitoriti nwọn kò mọ̀ ohùn
alejò.
6 Owe yi ni Jesu pa fun wọn: ṣugbọn
oyé nkan wọnni ti o fi nsọrọ fun wọn kò
yé wọn.
7 Nigbana ni Jesu tún wi fun wọn pe,
Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Emi ni ilẹ-
kun awọn agutan.
8 Olè ati ọlọṣà ni gbogbo awọn ti o ti
wá ṣiwaju mi: ṣugbọn awọn agutan kò gbọ́
ohùn wọn.
9 Emi ni ilẹkun: lati ọdọ mi bi ẹnikan
ba wọle, on li a o gbà là, on o wọle yio si
jade, yio si ri koriko.
10 Olè kì iwá, bikoṣe lati jale, ati lati
pa, ati lati parun: emi wá ki nwọn ki o le
ni ìye, ani ki nwọn ki o le ni i gidigidi
lọpọlọpọ.
11 Emi ni oluṣọ-agutan rere: oluṣọ-agu-
tan rere fi ẹmí rẹ̀ fun awọn agutan.
12 Ṣugbọn ẹniti iṣe alagbaṣe, ti kì iṣe
oluṣọ-agutan, ẹniti awọn agutan kì iṣe tirẹ̀,
o ri ikõkò mbọ̀, o fi agutan silẹ, o si sá lọ:
ikõkò si mu awọn agutan, o si fọn wọn ká
kiri.
13 Alagbaṣe sá lọ nitoriti iṣe alagbaṣe,
kò si náni awọn agutan.
14 Emi ni oluṣọ-agutan rere, mo si mọ̀
awọn agutan mi, mo si di mimọ̀ fun awọn
ti iṣe ti emi.
15 Gẹgẹ bi Baba ti mọ̀ mi, bẽni mo si
mọ̀ Baba: mo si fi ẹmí mi lelẹ fun awọn
agutan.
16 Emi si ni awọn agutan miran, ti kì
iṣe ti agbo yi: awọn li emi kò le ṣe alaimu
wá pẹlu, nwọn o si gbohùn mi; agbo kan,
ati oluṣọ-agutan kan ni yio si jẹ.
17 Nitorina ni Baba mi ṣe fẹ mi, nito-
riti mo fi ẹmí mi lelẹ, ki emi ki o le tún
gbà a.
18 Kò si ẹnikan ti ngbà a lọwọ mi, ṣu-
gbọn mo fi i lelẹ fun ara mi. Mo li agbara
lati fi i lelẹ, mọ si li agbara lati tún gbà
a. Aṣẹ yi ni mo ti gbà lati ọdọ Baba mi
wá.
19 ¶ Nitorina iyapa si tùn wà larin awọn
Ju nitori ọ̀rọ wọnyi.
20 Ọ̀pọ ninu wọn si wipe, O li ẹmi ẽṣu,
ori rẹ̀ si bajẹ; ẽṣe ti ẹnyin fi ngbọ̀rọ
rẹ̀?

Digitized by Google

21 Awọn miran wipe, Wọnyi kì iṣe ọ̀rọ
ẹniti o li ẹmi èṣu. Ẹmi èṣu le là oju awọn
afọju bi?
22 ¶ O si jẹ pe ni Jerusalemu ni, ni ajọ
ìyasi-mimọ́, o si jẹ igba otutù.
23 Jesu si nrìn ni tempili, ni iloro
Solomoni.
24 Nigbana li awọn Ju wá duro yi i ká,
nwọn si wi fun u pe, Iwọ o ti mu wa ṣe
iyemeji pẹ to? Bi iwọ ni iṣe Kristi na, wi
fun wa gbangba.
25 Jesu si da wọn lohùn wipe, Emi ti
wi fun nyin, ẹnyin kò si gbagbọ́: iṣẹ ti
mo ṣe li orukọ Baba mi, awọn ni njẹri
mi.
26 Ṣugbọn ẹnyin kò gbagbọ́, nitoriti
ẹnyin kì iṣe agutan mi, gẹgẹ bi mo ti wi
fun nyin.
27 Awọn agutan mi ngbọhùn mi, emi si
mọ̀ wọn, nwọn a si ma tọ̀ mi lẹhin:
28 Emi si fun wọn ni ìye ainipẹkun;
nwọn kì o si ṣegbé lailai, kò si si ẹniti o le
já wọn kuro li ọwọ́ mi,
29 Baba mi, ẹniti o fi wọn fun mi, pọ̀ju
gbogbo wọn lọ; kò si si ẹniti o le já wọn
kuro li ọwọ́ Baba mi.
30 Ọkan li emi ati Baba mi jasi.
31 Nigbana li awon Ju si tún he okuta,
lati sọ lù u.
32 Jesu da wọn lohùn pe, Ọ̀pọlọpọ iṣẹ
rere ni mo fi hàn nyin lati ọdọ Baba mi
wá; ninu iṣẹ wọnni nitori ewo li ẹnyin ṣe
nsọ mi li okuta?
33 Awọn Ju si da a lohùn, wipe, Awa
kò sọ ọ li okuta nitori iṣẹ rere; ṣugbọn
nitori sisọ̀rọ buburu si Ọlọrun; ati nitori
iwọ ti iṣe enia nfi ara rẹ ṣe Ọlọrun.
34 Jesu da wọn lohùn pe, A kò ha ti kọ
ọ ninu ofin nyin pe, Mo ti wipe, Ọlọrun li
ẹnyin iṣe?
35 Njẹ bi o ba pè wọn li ọmọ Ọlọrun,
awọn ẹniti a fi ọ̀rọ Ọlọrun fun, a kò si le ba
Iwe mimọ́ jẹ;
36 Ẹniti Baba ti yà si mimọ́, ti o si rán
wá aiye li ẹnyin nwipe, Iwọ nsọ̀rọ buburu
si Ọlọrun; nitoriti mo wipe, Ọmọ Ọlọrun
li emi iṣe?
37 Bi emi kò ba ṣe iṣẹ Baba mi, ẹ máṣe
gbà mi gbọ́.
38 Ṣugbọn bi emi ba ṣe wọn, bi ẹnyin
kò tilẹ gbà mi gbọ́, ẹ gbà iṣẹ na gbọ́: ki
ẹnyin ki o le mọ̀, ki ẹnyin ki o si le
gbagbọ́ pe, Baba wà ninu mi, emi si wà
ninu rẹ̀.
39 Nitorina nwọn si tún nwá ọ̀na lati
mu u: ṣugbọn o bọ lọwọ wọn,
40 O si tún kọja lọ soke odò Jordani
niha ibiti Johannu ti kọ baptisi ri; nibẹ̀ li
o si joko.
41 Awọn enia pipọ si wá sọdọ rẹ̀, nwọn
si wipe, Johannu ko ṣe iṣẹ iyanu kan:
ṣugbọn otitọ li ohun gbogbo ti Johannu sọ
nipa ti ọkọnrin yi.
42 Awọn enia pipọ nibẹ̀ si gbà a gbọ́.

## ORI 11.

ARA ọkọnrin kan si ṣe alaida, ẹniti a npè
ni Lasaru, ara Betani, ti iṣe ilu Maria
ati Marta arabirin rẹ̀.
2 (O si jẹ Maria na ẹniti o fi ohun ikunra
kùn Oluwa, ti o si fi irun ori rẹ̀ nù ẹsẹ rẹ̀
nù, arakọnrin rẹ̀ ni Lasaru iṣe, ara ẹniti kò
da.)
3 Nitorina awọn arabirin rẹ̀ ranṣẹ si
i, wipe, wò o, Oluwa, ara ẹniti iwọ fẹ kò
da.
4 Nigbati Jesu gbọ́, o wipe, Àrun yi kì
iṣe ti ikú, ṣugbọn fun ogo Ọlọrun, ki a le
yìn Ọmọ Ọlọrun logo nitori rẹ̀.
5 Jesu si fẹran Marta, ati arabirin rẹ̀,
ati Lasaru.
6 Nitorina nigbati o ti gbọ́ pe, ara rẹ̀
kò da, o gbé ijọ meji nibikanna ti o gbé
wà.
7 Lẹhin eyini li o wi fun awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ pe, Ẹ jẹ ki a si tún pada lọ si
Judea.
8 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si wi fun u pe,
Baba, nijelo yi li awọn Ju nwá ọ̀na ati sọ ọ
li okuta; iwọ si ntún pada lọ sibẹ̀?
9 Jesu si dahùn pe, Wakati mejila ki
mbẹ ninu ọsán kan? Bi ẹnikan ba rìn
li ọsán, kì yio kọsẹ̀, nitoriti o ri imọlẹ
aiye yi.
10 Ṣugbọn bi ẹnikan ba rìn li oru, yio
kọsẹ̀, nitoriti kò si imọlẹ ninu rẹ̀.
11 Nkan wọnyi li o sọ: lẹhin eyini o si
wi fun wọn pe, Lasaru ọrẹ́ wa sùn; ṣu-
gbọn emi nlọ ki emi ki o le jí i dide ninu
orun rẹ̀.
12 Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wi fun
u pe, Oluwa, bi o ba ṣepe o sùn, on o sàn.
13 Ṣugbọn Jesu nsọ ti ikú rẹ̀: ṣugbọn
nwọn rò pe, o nsọ ti orun sisun.
14 Nigbana ni Jesu wi fun wọn gbangba
pe, Lasaru kú.
15 Emi si yọ̀ nitori nyin, ti emi kò si
nibẹ̀, ki ẹnyin ki o le gbagbọ́; ṣugbọn ẹ jẹ
ki a lọ sọdọ rẹ̀.
16 Nigbana ni Tomasi, ẹniti a npè ni
Didimu, wi fun awọn ọmọ-ẹhin ẹgbẹ rẹ̀ pe,
Ẹ jẹ ki a lọ, ki a le ba a kú pẹlu.

Digitized by Google

17 Nitorina nigbati Jesu de, o ri pe a ti tẹ́ ẹ sinu iboji ni ijọ mẹrin na.

18 Ṣugbọn Betani sunmọ eti Jerusalemu to ìwọn stadia (furlongi) mẹdogun:

19 Ọpọ ninu awọn Ju si wá sọdọ Marta ati Maria, lati tù wọn ninu nitori arakọnrin wọn.

20 Nitorina bi Marta si ti gbọ́ pe Jesu mbọ̀ wá, o jade lọ ipade rẹ̀: ṣugbọn Maria joko ninu ile.

21 Nigbana ni Marta wi fun Jesu pe, Oluwa, ibaṣepe iwọ ti wà nihin, arakọnrin mi kì ba kú.

22 Ṣugbọn nisisiyi na, emi mọ̀ pe, ohunkohun ti iwọ ba bère lọwọ Ọlọrun, Ọlọrun yio fi i fun ọ.

23 Jesu wi fun u pe, Arakọnrin rẹ yio jinde.

24 Marta wi fun u pe, emi mọ̀ pe yio jinde li ajinde nigbẹhin ọjọ.

25 Jesu wi fun u pe Emi ni ajinde, ati ìye: ẹniti o ba gbà mi gbọ́, bi o tilẹ kú, yio si yè:

26 Ẹnikẹni ti o mbẹ lãye, ti o si gbà mi gbọ́, kì yio kú lailai. Iwọ gbà eyi gbọ́?

27 O wi fun u pe, Bẹ̃ni, Oluwa: emi gbagbọ́ pe, iwọ ni Kristi na Ọmọ Ọlọrun, ẹniti mbọ̀ wá aiye.

28 Nigbati o si ti wi eyi tan, o lọ, o si pè Maria arabirin rẹ̀ si ìkọkọ, wipe, Olukọni de, o si npè ọ.

29 Bi o ti gbọ́ eyini, lojukanna o dide lọgan, o si wá sọdọ rẹ̀.

30 Jesu kò sá ti iwọ̀ ilu, ṣugbọn o wà nibikanna ti Marta pade rẹ̀.

31 Nitorina awọn Ju ti o wà ninu ile pẹlu rẹ̀, ti nwọn ntù u ninu, nigbati nwọn ri ti Maria dide kánkan, ti o si jade, nwọn tọ̀ ọ lẹhin, wipe, O nlọ si iboji lọ isọkun nibẹ̀.

32 Nigbati Maria si de ibiti Jesu gbé wà, ti o si ri i, o wolẹ lẹba ẹsẹ rẹ̀, o wi fun u pe, Oluwa, ibaṣepe iwọ ti wà nihin, arakọnrin mi kì ba kú.

33 Njẹ nigbati Jesu ri i, ti o nsọkun, ati awọn Ju ti o ba a wá nsọkun pẹlu rẹ̀, o kerora li ọkàn rẹ̀, inu rẹ̀ si bajẹ,

34 O si wipe, Nibo ni ẹnyin gbé tẹ́ ẹ si? Nwọn si wi fun u pe, Oluwa, wá wò o.

35 Jesu sọkun.

36 Nigbana li awọn Ju wipe, kiyesi i, bi o ti fẹràn rẹ̀ to!

37 Awọn ọkan ninu wọn si wipe, Ọkọnrin yi, ẹniti o là oju awọn afọju, kò le ṣe ti ọkọnrin yi kì ba fi kú?

38 Nigbana ni Jesu tún kerora ninu ara rẹ̀, o wá si iboji. O si jẹ ihò, a si gbé okuta le ẹnu-ọ̀na rẹ̀.

39 Jesu wipe, Ẹ gbé okuta na kuro. Marta, arabirin ẹniti o kú na wi fun u pe, Oluwa, on ti nrùn nisisiyi: nitoripe o di ijọ mẹrin ti o ti kú.

40 Jesu wi fun u pe, Emi kò ti wi fun ọ pe, bi iwọ ba jẹ gbagbọ́, iwọ o ri ogo Ọlọrun?

41 Nigbana ni nwọn gbé okuta na kuro nibiti a gbe tẹ́ okú na si. Jesu si gbé oju rẹ̀ soke, o si wipe, Baba, mo dupẹ lọwọ rẹ, nitoriti iwọ gbọ́ ti emi.

42 Emi si ti mọ̀ pe, iwọ ama gbọ́ ti emi nigbagbogbo: ṣugbọn nitori awọn enia ti o duro yi ni mo ṣe wi i, ki nwọn ki o le gbagbọ́ pe iwọ li o rán mi.

43 Nigbati o si ti wi bẹ̃ tan, o kigbe li ohùn rara pe, Lasaru, jade wá.

44 Ẹniti o kú na si jade wá, ti a dì ti ọwọ́ ti ẹsẹ li aṣọ okú, a si fi gèle dì i loju. Jesu wi fun wọn pe, Ẹ tú u, ẹ si jẹ ki o ma lọ.

45 Nitorina li ọ̀pọ awọn Ju ti o ba Maria wá, nigbati nwọn ri ohun ti Jesu ṣe, gbà a gbọ.

46 Ṣugbọn awọn ẹlomiran ba ọ̀na wọn lọ sọdọ awọn Farisi, nwọn si sọ fun wọn li ohun ti Jesu ti ṣe.

47 ¶ Nigbana li awọn olori alufa ati awọn Farisi papejọ, nwọn si wipe, Kili awa nṣe? nitori ọkọnrin yi nṣe iṣẹ iyanu ọ̀pọlọpọ.

48 Bi awa ba jọwọ rẹ̀ bẹ̃, gbogbo enia ni yio gbà a gbọ́: awọn ará Romu yio si wá gbà ilẹ ati orilẹ-ède wa pẹlu.

49 Ọkan ninu wọn ti a npè ni Kaiafa, ẹniti iṣe olori alufa li ọdún na, o wi fun wọn pe, Ẹnyin kọ̀ mọ̀ ohunkohun rara.

50 Ẹ kò si rònu pe, o ṣànfani fun wa, ki ẹnikan kú fun awọn enia, ki gbogbo orilẹ-ède ki o má bà ṣegbé.

51 Eyi li o sọ kì iṣe fun ara rẹ̀: ṣugbọn bi o ti ṣe olori alufa li ọdún na, o sọtẹlẹ pe, Jesu yio kú fun orilẹ-ède na:

52 Kì si iṣe kìki fun orilẹ-ède na nikan, ṣugbọn pẹlu ki o le kó wọn jọ pọ̀ li ọkanṣoṣo, gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun ti a ti fọn ká kiri.

53 Njẹ lati ọjọ na lọ ni nwọn ti jọ gbìmọ̀ pọ̀ lati pa a.

54 Nitorina Jesu kò si rìn nigbangba larin awọn Ju mọ́; ṣugbọn o ti ibẹ̀ lọ si ilẹ kan ti o sunmọ aginjù, si ilu-nla kan ti a npè ni Efraimu, nibẹ̀ li o si wà pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ.

Digitized by Google

55 ¶ Ajọ irekọja awọn Ju si sunmọ
etile: ọ̀pọlọpọ ti o ti igberiko wá li o si
gòke lọ si Jerusalemu ṣiwaju irękọja, lati
yà ara wọn si mimọ́.
56 Nigbana ni nwọn nwá Jesu, nwọn si
mba ara wọn sọ, bi nwọn ti duro ni tempili
wipe, Ẹnyin ti rò o si? pe on ki yio wá si
ajọ?
57 Nitori awọn olori alufa ati awọn
Farisi ti paṣẹ pe, bi ẹnikan ba mọ̀ ibi ti o
gbé wà, ki o fi i hàn, ki nwọn ki o le mu u.

## ORI 12.

NIGBATI ajọ irekọja kù ijọ mẹfa, Jesu
wá si Betani, nibiti Lasaru wà, ẹniti
o ti kú, ti Jesu jinde kuro ninu okú.
2 Nibẹ̀ ni nwọn gbé se áse alẹ fun u;
Marta si nṣe iranṣẹ: ṣugbọn Lasaru jẹ
ọkan ninu awọn ẹniti o joko nibi tabili
pẹlu rẹ̀.
3 Nigbana ni Maria mu ikunra nardi,
oṣuwọn litra kan, ailabula, olowo iyebiye,
o si nfi kùn Jesu li ẹsẹ, o si nfi irun ori
rẹ̀ nù ẹsẹ rẹ̀ nù: ile si kún fun õrùn
ikunra na.
4 Nigbana li ọkan ninu awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀, Judasi Iskariotu, ọmọ Simoni,
ẹniti yio fi i hàn, wipe,
5 Eṣe ti a kò tà ikunra yi ni ọ̃durun
owo idẹ ki a si fifun awọn talakà?
6 O wi bayi, ki iṣe pe nitoriti o náni
awọn talakà; ṣugbọn nitoriti iṣe olè, on si
li àpo, a si ma gbé ohun ti a fi sinu rẹ̀.
7 Nigbana ni Jesu wipe, Ẹ jọwọ rẹ̀ si:
on ṣe eyi silẹ dè ọjọ sisinku mi.
8 Nigbagbogbo li ẹnyin sá ni talakà
pẹlu nyin; ṣugbọn ẹnyin kò ni mi nigba-
gbogbo.
9 Nitorina ọ̀pọ awọn Ju li o mọ̀ pe o wà
nibẹ̀: nwọn si wá sibẹ̀, ki iṣe nitori Jesu
nikan, ṣugbọn ki nwọn le ri Lasaru pẹlu,
ẹniti o ti jí dide kuro ninu okú.
10 ¶ Ṣugbọn awọn olori alufa gbìmọ bi
bi nwọn iba ti ṣe pa Lasaru pẹlu;
11 Nitoripe nipasẹ rẹ̀ li ọ̀pọ ninu awọn
Ju jade lọ, ti nwọn si gbà Jesu gbọ́.
12 ¶ Ni ijọ keji ọ̀pọ awọn enia ti o wá
si ajọ, nigbati nwọn gbọ́ pe, Jesu mbọ̀ wá
si Jerusalemu,
13 Nwọn bẹ́ imọ̀ ọpẹ, nwọn si jade lọ
ipade rẹ̀, nwọn si nkigbe pe, Hosanna:
Olubukun li Ọba Israeli ti o mbọ̀ wá li
orukọ Oluwa.
14 Nigbati Jesu si ri ọmọ kẹtẹkẹtẹ kan,
o gùn u; gẹgẹ bi a ti kọwe pe,
15 Má bẹ̀ru, ọmọbirin Sioni: kiyesi i,
Ọba rẹ mbọ̀ wá, o joko lori ọmọ kẹtẹkẹtẹ.
16 Nkan wọnyi kò tète yé awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀: ṣugbọn nigbati a ṣe Jesu logo,
nigbana ni nwọn ranti pe, a kọwe nkan
wọnyi nitori rẹ̀, ati pe, on ni nwọn ṣe
nkan wọnyi si.
17 Nitorina awọn enia ti o wà pẹlu rẹ̀,
nigbati o pè Lasaru jade ninu iboji rẹ̀, ti o
si jí i dide kuro ninu okú, nwọn jẹri.
18 Nitori eyi na li awọn enia ṣe lọ ipade
rẹ̀, nitori nwọn gbọ́ pe o ti ṣe iṣẹ iyanu yi.
19 Nitorina awọn Farisi wi fun ara wọn
pe, Ẹ kò kiyesi bi ẹnyin kò ti le bori li
ohunkohun? ẹ wò bi gbogbo aiye ti nwọ́
tọ̀ ọ.
20 ¶ Awọn Hellene kan si wà pẹlu wọn,
ti o gòke wá lati sìn nigba ajọ:
21 Awọn na li o tọ̀ Filippi wá, ti iṣe
ará Betsaida ti Galili, nwọn si mbère lọwọ
rẹ̀, wipe, Alàgba, awa nfẹ ri Jesu.
22 Filippi wá, o si sọ fun Anderu; ati
Anderu ati Filippi si sọ fun Jesu.
23 ¶ Jesu si da wọn lohùn wipe, Waka-
ti na de, nigbati a o ṣe Ọmọ-enia logo.
24 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Biko-
ṣepe wóro alikama ba bọ́ silẹ, ti o ba si kú,
o wà on nikan: ṣugbọn bi o ba kú, a si so
ọ̀pọlọpọ eso.
25 Ẹnikẹni ti o ba fẹ ẹmí rẹ̀ yio sọ ọ nù;
ẹniti o ba si korira ẹmi rẹ̀ li aiye yi ni yio
si pa a mọ́ titi fi di iye ainipẹkun.
26 Bi ẹnikẹni ba nsìn mi, ki o ma tọ̀ mi
lẹhin: nibiti mo ba wà, nibẹ̀ ni iranṣẹ mi
yio ma gbé pẹlu: bi ẹnikẹni ba nsìn mi,
on ni Baba mi yio bù ọlá fun.
27 Nisisiyi li a npọ́n ọkàn mi lọju; kili
emi o si wi? Baba, gbà mi ninu wakati
yi: ṣugbọn nitori idi eyi na ni mo ṣe wá si
wakati yi.
28 Baba, ṣe orukọ rẹ logo. Nigbana li
ohùn kan ti ọrun wá, nwipe, Emi ti ṣe e
logo na, emi o si tún ṣe e logo.
29 Nitorina awọn enia ti o duro nibẹ̀, ti
nwọn gbọ́ ohùn na, wipe, Ãrá nsán: awọn
ẹlomiran si wipe, Angeli kan li o nfọhùn
si i.
30 Jesu si dahùn wipe, Ohùn yi kò wá
nitori mi, bikoṣe nitori nyin.
31 Nigbayi ni idajọ aiye yi de: nigbayi
li a o lé ọmọ-alade aiye yi jade.
32 Ati emi, bi a ba gbé mi soke kuro li
aiye, emi o fà gbogbo enia sọdọ mi.
33 Ṣugbọn o wi eyi, o nṣapẹrẹ irú ikú ti
on o kú.
34 Awọn enia da a lohùn wipe, Awa

Digitized by Google

gbọ́ ninu ofin pe, Kristi wà lailai: iwọ si ti
ṣe wipe, A kò le ṣaima gbé Ọmọ-enia soke;
tani ṣe Ọmọ-enia yi?
35 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe,
Niwọn igba diẹ si i ni imọlẹ wà lọdọ nyin.
Ẹ mã rìn nigbati ẹnyin ni imọlẹ, ki òkun-
kun ki o máṣe wá sori nyin: nitori ẹniti
o ba nrìn li òkunkun kò mọ̀ ibiti on gbé
nlọ.
36 Niwọn igbati ẹnyin ni imọlẹ, ẹ gbà
imọlẹ gbọ́, ki ẹnyin ki o le jẹ ọmọ imọlẹ.
Nkan wọnyi ni Jesu sọ, o si jade lọ, o fi
ara rẹ̀ pamọ́ fun wọn.
37 ¶ Ṣugbọn bi o ti ṣe ọ̀pọlọpọ iṣẹ iyanu
to bayi li oju wọn, nwọn kò gbà a gbọ́;
38 Ki a le mu ọ̀rọ ti a ti ẹnu woli Isaiah
sọ ṣẹ, eyiti o wipe, Oluwa, tali o gbà iwasu
wa gbọ́? ati tali a si fi apá Oluwa hàn
fun?
39 Nitori eyi na ni nwọn kò fi le gba-
gbọ́, nitoriti Isaiah si tún wipe,
40 O ti fọ́ wọn loju, o si ti se àiya wọn
le; ki nwọn ki o má ba fi oju wọn ri, ki
nwọn ki o má ba fi àiya wọn mọ̀, ki a ma
ba yi wọn pada, ki emi ki o ma ba mu
wọn lara da.
41 Nkan wọnyi ni Isaiah wi, nigbati o
ri ogo rẹ̀, o si sọ̀rọ rẹ̀.
42 ¶ Ṣugbọn ọ̀pọ ninu awọn olori gbà a
gbọ́ pẹlu; ṣugbọn nitori awọn Farisi nwọn
kò jẹwọ rẹ̀, ki a máṣe lé wọn kuro ninu
sinagogu:
43 Nitori nwọn fẹ iyìn enia jù iyìn ti
Ọlọrun lọ.
44 ¶ Jesu kigbe o si wipe, Ẹnikẹni ti o
ba gbà mi gbọ́, kò gbà mi gbọ́, ṣugbọn ẹni-
ti o rán mi.
45 Ẹnikẹni ti o ba si ri mi, o ri ẹniti o
rán mi.
46 Emi ni imọlẹ ti o wá si aiye, ki ẹni-
kẹni ti o ba gbà mi gbọ́ ki o máṣe wà li
òkunkun.
47 Bi ẹnikẹni ba si gbọ́ ọ̀rọ mi, ti kò ba
si gbagbọ́, emi kì yio ṣe idajọ rẹ̀: nitoriti
emi kò wá lati ṣe idajọ araiye, bikoṣe lati
gbà wọn là.
48 Ẹnikẹni ti o ba kọ̀ mi, ti kò si gbà
ọ̀rọ mi, o ni ẹnikan ti nṣe idajọ rẹ̀: ọ̀rọ ti
mo ti sọ, on na ni yio ṣe idajọ rẹ̀ ni igbẹhin
ọjọ.
49 Nitori emi kò sọ̀rọ ti emi tikarami;
ṣugbọn Baba ti o rán mi, o ti fi aṣẹ fun mi,
ọ̀rọ ti emi o ma sọ, ati eyiti emi o ma wi.
50 Emi si mọ̀ pe ìye ainipẹkun li ofin
rẹ̀: nitorina, ohunkohun ti mo ba wi, gẹgẹ
bi Baba ti sọ fun mi, bẹ̃ni mo wi.

## ORI 13.

NJẸ ki ajọ irekọja ki o to de, nigbati
Jesu mọ̀ pe wakati rẹ̀ de tan, nigbati
on o ti aiye yi kuro lọ sọdọ Baba, fifẹ ti o
fẹ awọn tirẹ̀ ti o wà li aiye, o fẹ wọn titi
de opin.
2 Nigbati onjẹ alẹ si pari tan, nigbana li
Èṣu fi i si àiya Judasi Iskariotu ọmọ Simo-
ni lati fi i hàn;
3 Jesu si ti mọ̀ pe Baba ti fi ohun gbo-
gbo le on lọwọ, ati pe lọdọ Ọlọrun li on ti
wá, on si nlọ sọdọ Ọlọrun;
4 O dide ni idi onjẹ alẹ, o si fi agbáda rẹ̀
lelẹ li apakan; o si mu gèle, o di ara rẹ̀ li
àmure.
5 Lẹhin eyini o bù omi sinu awokoto
kan, o si bẹ̀rẹ si ima wẹ̀ ẹsẹ awọn ọmọ-ẹhin
rẹ̀, o si nfi gèle ti o fi di àmure nù wọn.
6 Nigbana li o de ọdọ Simoni Peteru:
Peteru si wi fun u pe, Oluwa, iwọ nwẹ̀ mi
li ẹsẹ?
7 Jesu dahùn o si wi fun u pe, Ohun ti
emi nṣe iwọ kò mọ̀ nisisiyi; ṣugbọn iwọ o
mọ̀ ọ nikẹhin.
8 Peteru wi fun u pe, Iwọ kì yio wẹ̀ mi
li ẹsẹ lai. Jesu da a lohùn pe, Bi emi kò
ba wẹ̀ ọ, iwọ kò ni ipa lọdọ mi.
9 Simoni Peteru si wi fun u pe, Oluwa,
kì iṣe kìki ẹsẹ mi nikan, ṣugbọn ọwọ́ ati
ori mi pẹlu.
10 Jesu si wi fun u pe, Ẹniti a ti wẹ̀ kò
tun fẹ ju ki a wẹ̀ ẹsẹ rẹ̀, ṣugbọn o mọ́ nibi
gbogbo: ẹnyin si mọ́, ṣugbọn kì iṣe gbogbo
nyin.
11 Nitoriti o ti mọ̀ ẹniti yio fi on hàn;
nitorina li o ṣe wipe, Kì iṣe gbogbo nyin li
o mọ́.
12 Nitorina lẹhin igbati o wẹ̀ ẹsẹ wọn
tan, ti o si ti mu aṣọ rẹ̀, ti o tún joko, o
wi fun wọn pe, Ẹnyin mọ̀ ohun ti mo ṣe si
nyin?
13 Ẹnyin npè mi ni Olukọni ati Oluwa:
ẹnyin wi rere; bẹ̃ni mo jasi.
14 Njẹ bi emi ti iṣe Oluwa ati Olukọni
nyin ba nwẹ̀ ẹsẹ nyin; o tọ́ ki ẹnyin pẹlu
si ma wẹ̀ ẹsẹ ara nyin.
15 Nitorina ni mo ṣe fi apẹrẹ fun nyin,
ki ẹnyin ki o le ma ṣe gẹgẹ bi mo ti ṣe si
nyin.
16 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ọmọ-
ọdọ kò tobi jù baba rẹ̀ lọ; bẹ̃ni iranṣẹ kò
tobi jù ẹniti o rán a lọ.
17 Bi ẹnyin ba mọ̀ nkan wọnyi, alabu-
kun-fun ni nyin, bi ẹnyin ba nṣe wọn.
18 ¶ Kì iṣe gbogbo nyin li emi mba wi:

Digitized by Google

emi mọ̀ awọn ti mo yàn: ṣugbọn ki Iwe
mimọ́ ki o le ṣẹ, Ẹniti mba mi jẹun pọ̀ si
gbé gigĩsẹ rẹ̀ si mi.
19 Njẹ mo wi fun nyin nisisiyi, ki o to
de pe, nigbati o ba de, ki ẹnyin ki o le
gbagbọ́ pe emi ni.
20 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹniti o
ba gbà ẹnikẹni ti mo rán, o gbà mi; ẹniti
o ba si gbà mi o gbà ẹniti o rán mi.
21 Nigbati Jesu ti wi nkan wọnyi tan,
ọkàn rẹ̀ bajẹ ninu rẹ̀, o si jẹri, o si wipe,
Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin pe, ọkan ninu
nyin yio fi mi hàn.
22 Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ nwò ara
wọn loju, nwọn nṣiyemeji ẹniti o wi.
23 Njẹ nisisiyi ẹnikan nrọgun si àiya
Jesu, ọkan ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, ẹniti
Jesu fẹràn.
24 Nitorina ni Simoni Peteru ṣapẹrẹ si
i, ki o le bère tani iba ṣe ẹni ti o nwi.
25 Ẹniti o nrọgun li àiya Jesu na si wi
pe, Oluwa, tani iṣe?
26 Jesu dahùn wipe, On na ni, ẹniti mo
ba fi òkele fun nigbati mo ba fi run. Ni-
gbati o si fi i run tan, o fifun Judasi Iska-
riotu ọmọ Simoni.
27 Lẹhin òkele na ni Satani wọ̀ inu rẹ̀
lọ. Nigbana ni Jesu wi fun u pe, Ohun ti
iwọ nṣe nì, yara ṣe e kánkan.
28 Kò si si ẹnikan nibi tabili ti o mọ̀ idi
ohun ti o ṣe sọ eyi fun u.
29 Nitori awọn miran ninu wọn rò pe,
nitori Judasi li o ni àpo, on ni Jesu fi wi
fun u pe, Rà nkan wọnni ti a kò le ṣe alai-
ni fun ajọ na; tabi ki o le fi nkan fun
awọn talakà.
30 Nigbati o si ti gbà òkele na tan, o
jade lojukanna: oru sá ni.
31 ¶ Nitorina nigbati o jade lọ tan,
Jesu wipe, Nisisiyi li a o yìn Ọmọ-enia
logo, a o si yìn Ọlọrun logo ninu rẹ̀.
32 Bi a ba yìn Ọlọrun logo ninu rẹ̀,
Ọlọrun yio si yìn i logo ninu on tikararẹ̀,
yio si yìn i logo nisisiyi.
33 Ẹnyin ọmọde, nigba diẹ si i li emi
wà pẹlu nyin. Ẹnyin o wá mi: ati gẹgẹ
bi mo ti wi fun awọn Ju pe, Nibiti mo gbé
nlọ, ẹnyin kì o le wá; bẹni mo si wi fun
nyin nisisiyi.
34 Ofin titun kan ni mo fifun nyin, Ki
ẹnyin ki o fẹ ọmọnikeji nyin; gẹgẹ bi emi
ti fẹ nyin, ki ẹnyin ki o si fẹ ọmọnikeji
nyin.
35 Nipa eyi ni gbogbo enia yio fi mọ̀ pe,
ọmọ-ẹhin mi li ẹnyin iṣe, nigbati ẹnyin ba
ni ifẹ si ọmọnikeji nyin.
36 ¶ Simoni Peteru wi fun u pe Oluwa,
nibo ni iwọ nlọ? Jesu da a lohùn pe, Ni-
biti emi nlọ, iwọ ki o le tọ̀ mi nisisiyi;
ṣugbọn iwọ o tọ̀ mi nikẹhin.
37 Peteru wi fun u pe, Oluwa, ẽṣe ti emi
ki o fi le tọ̀ ọ nisisiyi? emi le fi ẹmí mi
lelẹ nitori rẹ.
38 Jesu da a lohùn wipe, Iwọ le fi ẹmí
rẹ lelẹ nitori mi? Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun
ọ, Akukọ kì yio kọ, ki iwọ ki o to sẹ́ mi
nigba mẹta.

## ORI 14.

E MAṢE jẹ ki ọkàn nyin bajẹ: ẹnyin
gbà Ọlọrun gbọ́, ẹ si gbà mi gbọ́
pẹlu.
2 Ninu ile Baba mi ọ̀pọlọpọ ibugbe li o
wà: ibamáṣe bẽni, emi iba ti sọ fun nyin.
Emi nlọ ipèse àye silẹ fun nyin.
3 Bi emi ba si lọ ipèse àye silẹ fun nyin,
emi o si tún pada wá, emi o si mu nyin lọ
sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà,
nibẹ̀ li ẹnyin o ma gbé pẹlu.
4 Ẹnyin mọ̀ ibi ti mo gbé nlọ, ẹnyin si
mọ̀ ọ̀na na pẹlu.
5 Tomasi wi fun u pe, Oluwa, awa kò
mọ̀ ibiti iwọ nlọ; awa o si ti ṣe le mọ̀ ọ̀na
na?
6 Jesu wi fun u pe, Emi li ọ̀na, ati otitọ,
ati iye: kò si ẹnikẹni ti o le wá sọdọ Baba,
bikoṣe nipasẹ mi.
7 Bi ẹnyin ba ti mọ̀ mi, ẹnyin iba si ti
mọ̀ Baba mi pẹlu: ati lati isisiyi lọ li
ẹnyin ti mọ̀ ọ, ẹnyin si ti ri i.
8 Filippi wi fun u pe, Oluwa, fi Baba na
hàn wa, o si to fun wa.
9 Jesu wi fun u pe, Bi akokò ti mo ba
nyin gbé ti pẹ to yi, iwọ kò si ti imọ̀ mi
sibẹ̀ Filippi? ẹnikẹni ti o ba ti ri mi, o ti
ri Baba tan; iwọ ha si ti ṣe wipe, Fi Baba
hàn wa?
10 Iwọ kò gbagbọ́ pe, Emi wà ninu
Baba, ati pe Baba wà ninu mi? ọ̀rọ ti mo
sọ fun nyin, emi kò sọrọ ti emi tikarami;
bikoṣe ti Baba ti ngbé inu mi, on ni nṣe
iṣẹ wọnni.
11 Ẹ gbà mi gbọ́ pe, emi wà ninu Baba,
ati Baba wà ninu mi: bikoṣe bẹ̃, ẹ gbà mi
gbọ́ nitori iṣẹ wọnni.
12 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹniti
o ba gbà mi gbọ́, iṣẹ ti mo ṣe on ni yio si
ṣe pẹlu; iṣẹ ti o si tobi jù wọnyi lọ ni yio
si ṣe; nitoriti emi lọ sọdọ Baba mi.
13 Ati ohunkohun ti ẹnyin o bère li
orukọ mi, on na li emi o ṣe, ki a le yìn
Baba logo ninu Ọmọ,

Digitized by Google

14 Bi ẹnyin ba bère ohunkohun li orukọ
mi, emi o ṣe e.
15 ¶ Bi ẹnyin ba fẹ mi, ẹ pa ofin mi
mọ́.
16 Emi o si bère lọwọ Baba, on o si fun
nyin li Olutunu miran, ki o le ma ba nyin
gbé titi lailai;
17 Ani Ẹmí Otitọ nì; ẹniti araiye kò le
gbà, nitoriti kò ri i, bẽni kò si mọ̀ ọ:
ṣugbọn ẹnyin mọ̀ ọ; nitoriti o ngbé inu
nyin, on o si ma wà ninu nyin.
18 Emi kì o fi nyin silẹ li alaini Baba:
emi o tọ̀ nyin wá.
19 Niwọn igba diẹ, aiye ki o si ri mi
mọ́; ṣugbọn ẹnyin ri mi: nitoriti mo wà
lãye, ẹnyin o si wà lãye pẹlu.
20 Li ọjọ na li ẹnyin o mọ̀ pe, emi wà
ninu Baba mi, ati ẹnyin ninu mi, ati emi
ninu nyin.
21 Ẹniti o ba li ofin mi, ti o ba si npa
wọn mọ́, on na li ẹniti o fẹ mi: ẹniti o ba
si fẹ mi, a o fẹ ẹ lati ọdọ Baba mi wá, emi
o si fẹ ẹ, emi o si fi ara mi hàn fun u.
22 Judasi wi fun u, (kì iṣe Iskariotu) pe,
Oluwa, iwọ o ti fi ara rẹ hàn fun wa, ti kì
yio si ṣe fun araiye?
23 Jesu dahùn o si wi fun u pe, Bi ẹni-
kan ba fẹ mi, on o si pa ọ̀rọ mi mọ́: Baba
mi yio si fẹ ẹ, awa o si ma tọ̀ ọ wá, awa o
si ṣe ibugbe wa pẹlu rẹ̀.
24 Ẹniti kò fẹ mi ni ko pa ọ̀rọ mi mọ́:
ati ọ̀rọ na ti ẹnyin gbọ́ ki iṣe ti emi, ṣugbọn
ti Baba ti o rán mi.
25 Nkan wọnyi li emi nsọ fun nyin,
niwọn igba ti mo wà pẹlu nyin.
26 Ṣugbọn Olutunu na, ti iṣe Ẹmí Mimọ́,
ẹniti Baba yio rán li orukọ mi, on ni yio
kọ́ nyin li ohun gbogbo, yio si mu ohun
gbogbo wá si iranti nyin, ohunkohun ti mo
ti sọ fun nyin.
27 Alafia ni mo fi silẹ fun nyin, alafia
mi ni mo fifun nyin: kì iṣe gẹgẹ bi aiye ti
fi funni ni mo fifun nyin. Ẹ máṣe jẹ ki
ọkàn nyin bajẹ, ẹ má si jẹ ki o warìri.
28 Ẹnyin sá ti gbọ́ bi mo ti wi fun nyin
pe, Emi nlọ, emi o si tún pada tọ̀ nyin wá.
Ẹnyin iba fẹ mi, ẹnyin iba ma yọ̀ nitoriti
mo wipe, Emi nlọ sọdọ Baba: nitoriti Baba
mi tobi jù mi lọ.
29 Emi si ti wi fun nyin tẹlẹ nisisiyi ki
o to de, nigbati o ba de, ki ẹnyin ki o le
gbagbọ́.
30 Lẹhin eyi emi kì o sọ ọ̀rọ pipọ fun
nyin: nitori alade aiye yi wá, kò si ni
nkan kan lọdọ mi.
31 Ṣugbọn nitori ki araiye ki o le mọ̀ pe
emi fẹ Baba; gẹgẹ bi Baba si ti fi aṣẹ fun
mi, bẽni mo si ṣe. Ẹ dide, ẹ jẹ ki a lọ kuro
nihinyi.

## ORI 15.

EMI ni àjara otitọ, Baba mi si ni oluṣọ-
gba.
2 Gbogbo ẹká ninu mi ti kò ba so eso,
on a'mu u kuro: ati gbogbo ẹká ti o ba so
eso, on a wẹ̀ ẹ mọ́, ki o le so eso lọpọlọpọ.
3 Ẹnyin di mimọ́ nisisiyi nipa ọ̀rọ ti mo
ti sọ fun nyin.
4 Ẹ ma gbé inu mi, emi o si ma gbé inu
nyin. Gẹgẹ bi ẹká kò ti le so eso fun ara
rẹ̀, bikoṣepe o ba ngbé inu àjara; gẹgẹ bẽli
ẹnyin kò le ṣe e, bikoṣepe ẹnyin ba ngbé
inu mi.
5 Emi ni àjara, ẹnyin ni ẹká. Ẹniti o
ba ngbé inu mi, ati emi ninu rẹ̀, on ni yio
so eso ọ̀pọlọpọ: nitori yiyara nyin kuro
lọdọ mi, ẹnyin kò le ṣe ohunkohun.
6 Bi ẹnikan kò ba gbé inu mi, a si mu u
kuro gẹgẹ bi ẹká, a si gbẹ; nwọn a si kó
wọn jọ, nwọn a si wọ́ wọn jù sinu iná, nwọn
a si jóna.
7 Bi ẹnyin ba ngbé inu mi, ti ọ̀rọ mi ba
si ngbé inu nyin, ẹnyin o bère ohun ti ẹnyin
fẹ, a o si ṣe e fun nyin.
8 Ninu eyi li a sá nyin Baba mi logo pe,
ki ẹnyin ki o ma so eso pupọ; bẽli ẹnyin o
jẹ ọmọ ẹhin mi.
9 Gẹgẹ bi Baba ti fẹ mi, bẽli emi si fẹ
nyin: ẹ duro ninu ifẹ mi.
10 Bi ẹnyin ba pa ofin mi mọ́, ẹnyin o
duro ninu ifẹ mi; gẹgẹ bi mo ti pa ofin
Baba mi mọ́, mo si duro ninu ifẹ rẹ̀.
11 Nkan wọnyi ni mo sọ fun nyin, ki
ayọ̀ mi ki o le duro ninu nyin, ati ki ayọ̀
nyin ki o le kún.
12 Eyi li ofin mi, pe ki ẹnyin ki o fẹ
ọmọnikeji nyin, gẹgẹ bi mo ti fẹ nyin.
13 Ẹnikẹni kò ni ifẹ ti o tobijù eyi lọ,
pe ẹnikan fi ẹmí rẹ̀ lelẹ nitori awọn ọrẹ́ rẹ̀.
14 Ọrẹ́ mi li ẹnyin iṣe, bi ẹnyin ba ṣe
ohunkohun ti mo pa laṣẹ fun nyin.
15 Lati isisiyi lọ emi kò pè nyin li ọmọ-
ọdọ mọ́; nitori ọmọ-ọdọ kò mọ̀ ohun ti
oluwa rẹ̀ nṣe: ṣugbọn emi pè nyin li ọrẹ́;
nitori ohun gbogbo ti mo ti gbọ́ lati ọdọ
Baba mi wá, mo si ti fi hàn fun nyin.
16 Ki iṣe ẹnyin li o yàn mi, ṣugbọn emi
li o yàn nyin, mo si ṣe ìlana nyin, ki ẹnyin
ki o le lọ, ki ẹ si so eso, ki eso nyin ki o le
duro; ki ohunkohun ti ẹnyin ba bère lọwọ
Baba li orukọ mi, ki o le fi i fun nyin.

Digitized by Google

17 Nkan wọnyi ni mo pa laṣẹ fun nyin
pe, ki ẹnyin ki o fẹ ọmọnikeji nyin.
18 Bi aiye ba korira nyin, ẹnyin mọ̀ pe,
o korira mi, ki o to korira nyin.
19 Ibaṣepe ẹnyin ṣe ti aiye, aiye iba fẹ
awọn tirẹ̀ ; ṣugbọn nitoriti ẹnyin kì iṣe ti
aiye, ṣugbọn emi ti yàn nyin kuro ninu
aiye, nitorina li aiye ṣe korira nyin.
20 Ẹ ranti ọ̀rọ ti mo ti sọ fun nyin pe,
Ọmọ-ọdọ kò tobi jù oluwa rẹ̀ lọ. Bi nwọn
ba ti ṣe inunibini si mi, nwọn o ṣe inuni-
bini si nyin pẹlu : bi nwọn ba pa ọ̀rọ mi
mọ́, nwọn o si pa ti nyin mọ́ pẹlu.
21 Ṣugbọn gbogbo nkan wọnyi ni nwọn
o ṣe si nyin, nitori orukọ mi, nitoriti nwọn
kò mọ̀ ẹniti o rán mi.
22 Ibaṣepe emi kò ti wá lati sọ fun wọn,
nwọn kì ba ti li ẹ̀ṣẹ : ṣugbọn nisisiyi nwọn
di alairiwi nitori ẹ̀ṣẹ wọn.
23 Ẹniti o ba korira mi, o korira Baba
mi pẹlu.
24 Ibaṣepe emi kò ti ṣe iṣẹ na larin wọn,
ti ẹlomiran kò ṣe ri, nwọn kì ba ti li ẹ̀ṣẹ :
ṣugbọn nisisiyi nwọn ti ri, nwọn si korira
ati emi ati Baba mi.
25 Ṣugbọn eyi ṣe ki ọ̀rọ ti a kọ ninu ofin
wọn ki o le ṣẹ, Nwọn korira mi li ainidi.
26 Ṣugbọn nigbati Olutunu na ba de,
ẹniti emi o rán si nyin lati ọdọ Baba wá,
ani Ẹmí otitọ nì, ẹniti nti ọdọ Baba wá,
on o si jẹri mi :
27 Ati ẹnyin pẹlu o si jẹri mi, nitoriti
ẹnyin ti wà pẹlu mi lati ipilẹṣẹ wa.

## ORI 16.

NKAN wọnyi ni mo ti sọ fun nyin, ki a
má ba mu nyin kọsẹ̀.
2 Nwọn o lé nyin kuro ninu sinagogu :
ani, akokò na mbọ̀, nigbati ẹnikẹni ti
o ba pa nyin, yio rò pe on nṣe ìsin fun
Ọlọrun.
3 Ati gbogbo nkan wọnyi ni nwọn o ṣe
si nyin, nitoriti nwọn kò mọ̀ Baba, nwọn
kò si mọ̀ mi.
4 Ṣugbọn nkan wọnyi ni mo ti wi fun
nyin pe, nigbati akokò na ba de, ki ẹnyin
ki o le ranti pe, mo ti sọ fun nyin nitori
wọn. Ṣugbọn emi ko sọ nkan wọnyi fun
nyin lati ipilẹṣẹ wá, nitoriti mo wà pẹlu
nyin.
5 Ṣugbọn nisisiyi emi nlọ sọdọ ẹniti o
rán mi ; kò si si ẹnikan ninu nyin ti o bi
mi lẽre pe, Nibo ni iwọ nlọ ?
6 Ṣugbọn nitoriti mo sọ nkan wọnyi fun
nyin, ibinujẹ si kún ọkàn nyin.
7 Ṣugbọn li otitọ ni mo wi fun nyin ;
Anfani ni fun nyin bi mo ba lọ : nitori
bi emi kò ba lọ, Olutunu kì o tọ̀ nyin
wá ; ṣugbọn bi mo ba lọ, emi o rán a si
nyin.
8 Nigbati o ba si de, yio fi oyé yé araiye
nipa ti ẹ̀ṣẹ, ati nipa ti ododo, ati nipa ti
idajọ :
9 Nipa ti ẹ̀ṣẹ, nitoriti nwọn kò gbà mi
gbọ́ ;
10 Nipa ti ododo, nitoriti emi nlọ sọdọ
Baba mi, ẹnyin kò si ri mi mọ́ ;
11 Nipa ti idajọ, nitoriti a ti ṣe idajọ
alade aiye yi.
12 Mo ni nkan pipọ lati sọ fun nyin
pẹlu, ṣugbọn ẹnyin kò le gbà wọn nisisiyi.
13 Ṣugbọn nigbati on, ani Ẹmí otitọ nì
ba de, yio tọ́ nyin si ọ̀na otitọ gbogbo :
nitori on kì o sọ̀rọ ti on tikararẹ̀ ; ṣugbọn
ohunkohun ti o ba gbọ́, on ni yio ma sọ :
yio si fi ohun ti mbọ̀ hàn nyin.
14 On o ma yìn mi logo : nitoriti yio
gbà ninu ti emi, yio si ma fi hàn fun
nyin.
15 Ohun gbogbo ti Baba ní ti emi ni :
nitorina ni mo ṣe wipe, on o mu ohun ti
emi, yio si fi hàn fun nyin.
16 Niwọn igba diẹ, ẹnyin kì o si ri mi :
ati niwọn igba diẹ ẹ̀wẹ, ẹnyin o si ri mi,
nitoriti emi nlọ sọdọ Baba.
17 Nigbana li omiran ninu awọn ọmọ-
ẹhin rẹ̀ mba ara wọn ṣe aroye pe, Kili eyi
ti o wi fun wa yi, Niwọn igba diẹ, ẹnyin
kì o si ri mi : ati niwọn igba diẹ ẹ̀wẹ,
ẹnyin o si ri mi : ati Nitoriti emi nlọ sọdọ
Baba ?
18 Nitorina nwọn wipe, Kili eyi ti o wi
yi, Niwọn igba diẹ ? awa kò mọ̀ ohun ti o
wi.
19 Jesu sá ti mọ̀ pe, nwọn nfẹ lati bi on
lẽre, o si wi fun wọn pe, Ẹnyin mbi ara
nyin lẽre niti eyi ti mo wipe, Niwọn igba
diẹ, ẹnyin kì o si ri mi : ati niwọn igba diẹ
ẹ̀wẹ, ẹnyin o si ri mi ?
20 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin pe,
Ẹnyin o ma sọkun, ẹ o si ma pohùnrere
ẹkún, ṣugbọn awọn araiye yio ma yọ̀ : inu
nyin yio si bajẹ, ṣugbọn ibinujẹ nyin li a o
sọ di ayọ̀.
21 Nigbati obirin bá wà ninu irọbi, a ni
ibinujẹ, nitoriti wakati rẹ̀ de : ṣugbọn ni-
gbati o ba ti bí ọmọ na tan, on kò si ranti
irora na mọ́, fun ayọ̀ nitori a bímọ enia si
aiye.
22 Nitorina ẹnyin ni ibinujẹ nisisiyi :
ṣugbọn emi o si tún ri nyin, ọkàn nyin yio

Digitized by Google

si yọ̀, kò si si ẹnikẹni ti yio gbà ayọ̀ nyin
lọwọ nyin.
23 Ati ni ijọ na ẹnyin kì o bi mi lẽre
ohunkohun. Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin,
Ohuǹkohun ti ẹnyin ba bère lọwọ Baba li
orukọ mi, on o fifun nyin.
24 Titi di isisiyi ẹnyin kò ti ibère ohun-
kohun li orukọ mi: bẹre ẹnyin o si ri gbà,
ki ayọ̀ nyin ki o le kún.
25 Nkan wọnyi ni mo ti fi owe sọ fun
nyin: ṣugbọn akokò na de, nigbati emi kì
yio fi owe sọ fun nyin mọ́, ṣugbọn emi o sọ
ti Baba fun nyin gbangba.
26 Li ọjọ na ẹnyin o bère li orukọ mi:
emi kò si wi fun nyin pe, emi o bère lọwọ
Baba fun nyin:
27 Nitoriti Baba tikararẹ̀ fẹ nyin, nito-
riti ẹnyin fẹ mi, ati ti ẹnyin si gbagbọ́ pe,
lọdọ Ọlọrun ni mo ti jade wá.
28 Emi jade lati ọdọ Baba wá, mo si wá
si aiye: mo fi aiye silẹ ẹ̀wẹ, mo si lọ sọdọ
Baba.
29 Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wi fun u pe, Ni-
gbayi ni iwọ nsọ̀rọ gbangba, iwọ kò si fi
owe sọ̀rọ.
30 Nigbayi li o to da wa loju pe, iwọ
mọ̀ ohun gbogbo, ati pe iwọ kò ni ki a bi ọ
lẽre: nipa eyi li awa gbagbọ́ pe, lọdọ Ọlọrun
ni iwọ ti jade wá.
31 Jesu da wọn lohùn pe, Ẹnyin gbagbọ́
nisisiyi bi?
32 Kiyesi i wakati na mbọ̀ wá, ani o de
tan nisisiyi, ti a o fọn nyin ká kiri, oluku-
luku si nkan ti on tikalarẹ̀; ẹnyin o si fi
emi nikan silẹ: ṣugbọn kì yio kù emi
nikan, nitoriti Baba mbẹ pẹlu mi.
33 Nkan wọnyi ni mo ti sọ fun nyin
tẹlẹ, ki ẹnyin ki o le ni alafia lọdọ mi.
Lọdọ araiye, ẹnyin o ni ipọnju, ṣugbọn ẹ
tújuka; mo ti ṣẹgun aiye na.

## ORI 17.

ỌRỌ wọnyi ni Jesu sọ, o si gbé oju rẹ̀
soke ọrun, o si wipe, Baba, wakati na
de: yìn Ọmọ rẹ logo, ki Ọmọ rẹ ki o le yìn
ọ logo pẹlu:
2 Gẹgẹ bi iwọ ti fun u li agbara lori ẹda
gbogbo, ki o le fi ìye ainipẹkun fun ìwọn
awọn ti o fifun u.
3 Ìye ainipẹkun na li eyi, ki nwọn ki o
le mọ̀ iwọ nikan Ọlọrun otitọ, ati Jesu
Kristi, ẹniti iwọ rán.
4 Emi ti yìn ọ logo li aiye: emi ti pari
iṣẹ na, ti iwọ fifun mi lati ṣe.
5 Njẹ nisisiyi, Baba, yìn mi logo pẹlu
ara rẹ, gẹgẹ bi ogo ti mo ti ni pẹlu rẹ ki
aiye ki o to wà.
6 Emi ti fi orukọ rẹ hàn fun awọn enia
ti iwọ fifun mi lati inu aiye jade wá: tirẹ
ni nwọn ti ṣe ri, iwọ si fi wọn fun mi;
nwọn si ti pa ọ̀rọ rẹ mọ́.
7 Nwọn si ti mọ̀ nisisiyi pe, ohunkohun
gbogbo ti iwọ ti fifun mi, tirẹ ni nwọn
iṣe.
8 Nitori emi ti fi ọ̀rọ na fun wọn ti iwọ
ti fifun mi; nwọn si ti gbà a, nwọn si ti
mọ̀ daju-daju pe, lọdọ rẹ li emi ti jade wá,
nwọn si ti gbagbọ́ pe iwọ li o rán mi.
9 Emi ngbadura fun wọn: emi kò gba-
dura fun araiye, ṣugbọn fun awọn ti iwọ ti
fifun mi; nitoripe tirẹ ni nwọn iṣe.
10 Tirẹ sá ni gbogbo awọn ti iṣe ti emi,
ati ti emi si ni gbogbo awọn tirẹ; a si yìn
mi logo ninu wọn.
11 Emi kò si si li aiye mọ́, awọn wọnyi
si mbẹ li aiye, emi si mbọ̀ wá sọdọ rẹ.
Baba mimọ́, pa awọn ti o ti fifun mi mọ́, li
orukọ rẹ, ki nwọn ki o le jẹ ọkan, gẹgẹ bi
awa ti jẹ ọkan.
12 Nigbati emi wà pẹlu wọn li aiye, mo
pa wọn mọ́ li orukọ rẹ: awọn ti iwọ fifun
mi, ni mo ti pamọ́, kò si si ẹnikẹni ti o nù
ninu wọn, bikoṣe ọmọ egbé; ki Iwe mimọ́
ki o le ṣẹ.
13 Emi si mbọ̀ wá sọdọ rẹ nisisiyi, nkan
wọnyi ni mo si nsọ li aiye, ki nwọn ki
o le ni ayọ̀ mi ni kikun ninu awọn tikara
wọn.
14 Emi ti fi ọ̀rọ rẹ fun wọn; aiye si ti
korira wọn, nitoriti nwọn kì iṣe ti aiye,
gẹgẹ bi emi kì iti iṣe ti aiye.
15 Emi ko gbadura pe, ki iwọ ki o le mu
wọn kuro li aiye, ṣugbọn ki iwọ ki o le pa
wọn mọ́ kuro ninu buburu rẹ̀.
16 Nwọn kì iṣe ti aiye, gẹgẹ bi emi kì ti
iṣe ti aiye.
17 Sọ wọn di mimọ́ nipa otitọ rẹ: otitọ
li ọ̀rọ rẹ.
18 Gẹgẹ bi iwọ ti rán mi wá si aiye, bẽ̀
gẹgẹ li emi si rán wọn si aiye pẹlu.
19 Emi si yà ara mi si mimọ́ nitori
wọn, ki a le sọ wọn di mimọ́ pẹlu nipa
otitọ.
20 Kì si iṣe kìki awọn li emi ngbadura
fun, ṣugbọn fun awọn ti yio gbà mi gbọ́
pẹlu nipa ọ̀rọ wọn;
21 Ki gbogbo wọn ki o le jẹ ọkan; gẹgẹ
bi iwọ, Baba, ti jẹ ọkan ninu mi, ati emi
ninu rẹ, ki awọn pẹlu ki o le jẹ ọkan ninu
wa: ki awọn araiye ki o le gbagbọ́ pe, iwọ
li o rán mi.

Digitized by Google

22 Ogo nì ti iwọ ti fifun mi li emi si ti fifun wọn; ki nwọn ki o le jẹ ọkan, gẹgẹ bi awa ti jẹ ọkan:
23 Emi ninu wọn, ati iwọ ninu mi, ki a le ṣe wọn pé li ọkan; ki araiye ki o le mọ̀ pe, iwọ li o rán mi, ati pe iwọ si fẹ wọn, gẹgẹ bi iwọ ti fẹ mi.
24 Baba, emi fẹ ki awọn ti iwọ fifun mi, ki o wà pẹlu mi, nibiti emi gbé wà; ki nwọn ki o le ri ogo mi, ti iwọ fi fifun mi: nitoriti iwọ sá ti fẹ mi ṣiwaju ipilẹṣẹ aiye.
25 Baba olododo, aiye kò mọ̀ ọ: ṣugbọn emi mọ̀ ọ, awọn wọnyi si mọ̀ pe iwọ li o rán mi.
26 Emi si ti fi orukọ rẹ hàn fun wọn, emi o si fi i hàn: ki ifẹ nipa eyi ti iwọ fẹ mi, ki o le ma wà ninu wọn, ati emi ninu wọn.

## ORI 18.

NIGBATI Jesu si ti sọ̀rọ wọnyi tan, o jade pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ lọ soke odò Kedroni, nibiti agbala kan wà, ninu eyi ti o wọ̀, ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀.
2 Ati Judasi, ẹniti o fi i hàn, si ti mọ̀ ibẹ̀ pẹlu: nitori nigbakugba ni Jesu ima lọ sibẹ̀ pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀.
3 Nigbana ni Judasi, ẹniti o ti gbà ọ̀wọ́ ọmọ-ogun, ati awọn onṣẹ lati ọdọ awọn olori alufa ati awọn Farisi, wá sibẹ̀ ti awọn ti fitilà ati ògụṣọ̀, pẹlu ihamọra.
4 Nitorina nigbati Jesu mọ̀ ohun gbogbo ti mbọ̀ wá ba on, o jade lọ, o si wi fun wọn pe, Tali ẹnyin nwá?
5 Nwọn si da a lohùn wipe, Jesu ti Nasareti. Jesu si wi fun wọn pe, Emi niyi. Ati Judasi pẹlu, ẹniti o fi i hàn, duro pẹlu wọn.
6 Bi Jesu si ti wi fun wọn pe, Emi niyi, nwọn pada sẹhin, nwọn si ṣubu lulẹ.
7 Nigbana li o si tún bi wọn lẽre, wipe, Tali ẹnyin nwá? Nwọn si wipe, Jesu ti Nasareti.
8 Jesu dahùn, Emi ti wi fun nyin pe, emi niyi: njẹ bi emi li ẹnyin ba nwá, ẹ jẹ ki awọn wọnyi ma ba ọ̀na ti wọn lọ:
9 Ki ọ̀rọ na ki o le ṣẹ, eyi ti o wipe, Ọkan ninu awọn ti iwọ fifun mi, emi kò sọnù.
10 Nigbana ni Simoni Peteru ẹniti o ni idà, o fà a yọ, o si ṣá ọkan ti iṣe ọmọ-ọdọ olori alufa, o si ke etí ọtún rẹ̀ sọnù. Orukọ iranṣẹ na ama jẹ Malku.
11 Nigbana ni Jesu wi fun Peteru pe, Tẹ̀ idà rẹ bọ inu àkọ rẹ̀: ago ti Baba mi ti fifun mi, emi o ṣe alaimu u bi?
12 Nigbana li awọn ọmọ-ogun, ati olori ẹṣọ́, ati onṣẹ awọn Ju mu Jesu, nwọn si dè e.
13 Nwọn tètekọ mu u lọ sọdọ Anna; nitori on ni iṣe ana Kaiafa, ẹniti iṣe olori alufa li ọdún na.
14 Kaiafa sá ni iṣe, ẹniti o ti ba awọn Ju gbìmọ pe, o yẹ ki ọkọnrin kan ba kú fun awọn enia.
15 ¶ Simoni Peteru si ntọ̀ Jesu lẹhin, gẹgẹ bẹ̃ li ọmọ-ẹhin kan miran si ṣe: ọmọ-ẹhin na jẹ ẹniti olori alufa mọ̀, o si ba Jesu wọ̀ afin olori alufa lọ.
16 Ṣugbọn Peteru duro li ẹnu-ọ̀na lode. Nigbana li ọmọ-ẹhin miran na, ẹniti olori alufa ti mọ̀, o jade lọ, o sọ fun ẹniti nṣọ ẹnu-ọ̀na, o si mu Peteru wọle.
17 Nigbana li ọmọbirin na ti nṣọ ẹnu-ọ̀na wi fun Peteru pe, Ọkan ninu awọn ọmọ-ẹhin ọkọnrin yi pẹlu kọ́ iwọ iṣe? O wipe, Emi kì iṣe on.
18 Awọn ọmọ-ọdọ ati awọn onṣẹ si duro nibẹ̀, awọn ẹniti o ti dana ẹyín; nitoriti o jẹ igba otutù: nwọn si nyána: Peteru si duro pẹlu wọn, o nyána.
19 ¶ Nigbana li olori alufa bi Jesu lẽre nipa ti awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, ati ti ẹkọ́ rẹ̀.
20 Jesu da a lohùn wipe, Emi nsọ̀rọ nigbangba fun araiye; nigbagbogbo li emi nkọ́ni ninu sinagogu, ati ni tempili nibiti awọn Ju ima pejọ nigbagbogbo; emi kò si sọ ohunkohun ni ìkọkọ.
21 Ẽṣe ti iwọ fi mbi mi lẽre? bi awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ mi, ohun ti mo wi fun wọn: kiyesi i nwọn mọ̀ ohun ti mo wi.
22 Bi o si ti wi bẹ̃ tan, ọkan ninu awọn onṣẹ, ti o duro leti ọdọ rẹ̀ si fi atẹlẹ ọwọ́ rẹ̀ gbá Jesu loju, wipe, Olori alufa ni iwọ nda lohùn bẹ̃?
23 Jesu da a lohùn wipe, Bi o ba ṣepe ibi ni mo wi, jẹri si ibi na: ṣugbọn bi rere ba ni, ẽṣe ti iwọ fi nlù mi?
24 Anna sá ti dè e, o si rán a lọ sọdọ Kaiafa olori alufa.
25 Simoni Peteru si duro, o nyána. Nigbana ni nwọn wi fun u pe, Ọkan ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pẹlu kọ́ iwọ iṣe? O si sẹ́, o wipe, Emi kì iṣe on.
26 Ọkan ninu awọn ọmọ-ọdọ olori alufa, ati ẹniti iṣe ibatan ẹniti Peteru ke etí rẹ̀ sọnù, wipe, koṣepe mo ri ọ pẹlu rẹ̀ li agbala?
27 Nigbana ni Peteru si tún sẹ́: lojukanna akukọ si kọ.

28 ¶ Nigbana ni nwọn mu Jesu lati ile Kaiafa lọ si ibi gbàngan idajọ: o si jẹ kutukutu owurọ̀; awọn tikara wọn kò wọ̀ inu gbàngan idajọ, ki nwọn ki o má ṣe di alaimọ́; ṣugbọn ki nwọn ki o le jẹ àse irekọja.

29 Nigbana ni Pilatu jade tọ̀ wọn lọ, o si wipe, Ẹsun kili ẹnyin ni si ọkọnrin yi?

30 Nwọn si dahùn wi fun u pe, Ibaṣepe on kì iṣe arufin, awa kì ba ti fà a le ọ lọwọ.

31 Nigbana ni Pilatu wi fun wọn pe, Ẹ mu u, ki ẹ ṣe idajọ rẹ̀ gẹgẹ bi ofin nyin. Nitorina li awọn Ju wi fun u pe, Kò tọ́ fun wa nipa ofin lati pa ẹnikẹni:

32 Ki ọ̀rọ Jesu na ki o le ba ṣẹ, eyiti o wipe, o nṣapẹrẹ irú ikú ti on o kú.

33 Nigbana ni Pilatu tún wọ̀ inu gbàngan idajọ lọ, o si pè Jesu, o si wi fun u pe, Ngbọ́, Ọba awọn Ju ni iwọ iṣe?

34 Jesu da a lohùn pe, Iwọ wi nkan yi fun ara rẹ, tabi ẹlomiran sọ ọ fun ọ nitori mi?

35 Pilatu dahùn wipe, Emi iṣe Ju bi? Awọn orilẹ-ède rẹ ati awọn olori alufa li o fà ọ le emi lọwọ: kini iwọ ṣe?

36 Jesu dahùn wipe, Ijọba mi kì iṣe ti aiye yi: ibaṣepe ijọba mi iṣe ti aiye yi, awọn ọmọ-ọdọ mi iba jà, ki a máṣe fi mi le awọn Ju lọwọ: ṣugbọn nisisiyi ijọba mi kì iṣe lati ihin lọ.

37 Nitorina Pilatu wi fun u pe, Njẹ iwọ ha ṣe ọba bi? Jesu dahùn wipe, Iwọ wipe, ọba li emi iṣe. Nitori eyi li a ṣe bí mi, ati nitori idi eyi ni mo si ṣe wá si aiye, ki emi ki o le jẹri si otitọ. Olukuluku ẹniti iṣe ti otitọ ngbọ́ ohùn mi.

38 Pilatu wi fun u pe, Kili otitọ? Nigbati o si ti wi eyi tan, o si tún jade tọ̀ awọn Ju lọ, o si wi fun wọn pe, Emi kò sá ri ẹ̀ṣẹ kan lọwọ rẹ̀ rara.

39 Ṣugbọn ẹnyin ni iṣe kan pe, ki emi ki o dá ọkan silẹ fun nyin nigba ajọ irekọja: nitorina ẹnyin nfẹ ki emi ki o dá Ọba awọn Ju silẹ fun nyin bi?

40 Nigbana ni gbogbo wọn si tún kigbe wipe, kì iṣe ọkọnrin yi, bikoṣe Barabba. Njẹ olè ni Barabba iṣe.

## ORI 19.

NITORINA ni Pilatu mu Jesu, o si nà a.

2 Awọn ọmọ-ogun si wun ade ẹgún, nwọn si fi de e li ori, nwọn si fi aṣọ igunwà elesè àluko wọ̀ ọ,

3 Nwọn si wipe, Alafia, Ọba awọn Ju! nwọn si fi ọwọ́ wọn gbá a loju.

4 Nitorina Pilatu tún jade, o si wi fun wọn pe, Kiyesi i, mo mu u jade tọ̀ nyin wá, ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe, emi kò ri ẹ̀ṣẹ kan lọwọ rẹ̀.

5 Nigbana ni Jesu jade wá, ti on ti ade ẹgún ati aṣọ igunwà, elesè àluko. Pilatu si wi fun wọn pe, Ẹ wò ọkọnrin na!

6 Nitorina nigbati awọn olori alufa, ati awọn onṣẹ ri i, nwọn kigbe wipe, Kàn a mọ agbelebu, kàn a mọ agbelebu. Pilatu wi fun wọn pe, Ẹ mu u, ki ẹ si kàn a mọ agbelebu: nitoriti emi ko ri ohun ẹ̀ṣẹ kan lọwọ rẹ̀.

7 Awọn Ju da a lohùn wipe, Awa li ofin kan, ati nipa ofin wa o yẹ lati kú, nitoriti o fi ara rẹ̀ ṣe Ọmọ Ọlọrun.

8 ¶ Nitorina nigbati Pilatu gbọ́ ọ̀rọ nì, o bẹru gidigidi;

9 O si tun wọ̀ inu gbàngan idajọ lọ, o si wi fun Jesu pe, Nibo ni iwọ ti wá? Ṣugbọn Jesu kò da a lohùn.

10 Nigbana ni Pilatu wi fun u pe, Iwọ kò fọhun si mi? iwọ kò mọ̀ pe, emi li agbara lati kàn ọ mọ agbelebu, emi si li agbara lati dá ọ silẹ?

11 Jesu dahùn wipe, Iwọ kì ba ti li agbara kan lori mi, bikoṣepe a fi i fun ọ lati oke wá: nitorina ẹniti o fà mi le ọ lọwọ li o ni ẹ̀ṣẹ pọ̀ju.

12 Lati igbana lọ ni Pilatu si tí nwá ọ̀na lati dá a silẹ: ṣugbọn awọn Ju kigbe, wipe, Bi iwọ ba jọwọ ọkọnrin yi lọwọ lọ, iwọ kì iṣe ọrẹ́ Kesari: ẹnikẹni ti o ba fi ara rẹ̀ ṣe ọba, o sọ̀rọ òdi si Kesari.

13 ¶ Nitorina nigbati Pilatu si ti gbọ́ irú ọ̀rọ nì, o mu Jesu jade wá, o si joko lori itẹ́ idajọ nibikan ti a npè ni Titẹ́okuta, ṣugbọn li ède Heberu, Gabbata.

14 O si jẹ ọjọ ipalẹmọ́ ajọ irekọja, nigba wakati ẹkẹfa: o si wi fun awọn Ju pe, Ẹ wò Ọba nyin!

15 Ṣugbọn nwọn kigbe wipe, Mu u kuro, mu u kuro, kàn a mọ agbelebu. Pilatu wi fun wọn pe, Emi o ha kàn Ọba nyin mọ agbelebu bi? Awọn olori alufa dahùn wipe, Awa kò li ọba kan bikoṣe Kesari.

16 Nigbana li o fà a le wọn lọwọ lati kàn a mọ agbelebu. Nwọn si mu Jesu, nwọn si fà a jade.

17 On si nrù agbelebu rẹ̀ lọ si ibi kan, ti a npè ni Ibi agbari, li ède Heberu ti a npè ni Golgota:

18 Nibiti nwọn gbé kàn a mọ agbelebu, ati awọn meji miran pẹlu rẹ̀, ekini li apa kan, ati ekeji li apa keji, Jesu si wà larin.

Digitized by Google

19 ¶ Pilatu si kọwe akọle kan, o fi le ori agbelebu na. Ohun ti a si kọ ni, JESU TI NASARETI ỌBA AWỌN JU.

20 Ọpọlọpọ awọn Ju li o kà iwe akọle yi: nitori ibi ti a gbé kàn Jesu mọ agbelebu sunmọ eti ilu: a si kọ ọ li ède Heberu, ati ti Hellene, ati ti Latini.

21 Nigbana li awọn olori alufa awọn Ju wi fun Pilatu pe, Máṣe kọ ọ pe, Ọba awọn Ju; ṣugbọn pe on li o wipe, Emi li Ọba awọn Ju.

22 Pilatu dahùn wipe, Ohun ti mo ti kọ tan, mo ti kọ tan.

23 ¶ Nigbana li awọn ọmọ-ogun, nigbati nwọn kàn Jesu mọ agbelebu tan, nwọn mu aṣọ rẹ̀, nwọn si pín wọn si ipa mẹrin, apakan fun ọmọ-ogun kọkan, ati ẹ̀wu rẹ̀ pẹlu: njẹ ẹ̀wu na kò li ojuran, nwọn wún u lati oke titi jalẹ.

24 Nitorina nwọn wi fun ara wọn pe, Ẹ má jẹ ki a fà a ya, ṣugbọn ki a ṣẹ gège nitori rẹ̀, ti ẹniti yio jẹ: ki Iwe mimọ́ ki o le ṣẹ, ti o wipe, Nwọn pín aṣọ mi fun ara wọn, nwọn si ṣẹ gège fun aṣọ ileke mi. Nkan wọnyi li awọn ọmọ-ogun ṣe.

25 ¶ Awọn ẹnikan si duro nibi agbelebu Jesu, iya rẹ̀, ati arabirin rẹ̀, Maria aya Kleofa, ati Maria Magdalene.

26 Nitorina nigbati Jesu ri iya rẹ̀, ati ọmọ-ẹhin na duro, ẹniti Jesu fẹràn, o wi fun iya rẹ̀ pe, Obirin, wò ọmọ rẹ!

27 Nigbana li o si wi fun ọmọ-ẹhin na pe, Wò iya rẹ! Lati wakati na lọ li ọmọ-ẹhin na si ti mu u lọ si ile ara rẹ̀.

28 ¶ Lẹhin eyi, bi Jesu ti mọ̀ pe, a si ti pari ohun gbogbo tan, ki Iwe mimọ́ ki o le ba ṣẹ, o wipe, Orungbẹ ngbẹ mi.

29 A ti gbé ohun-èlo kan kalẹ nibẹ̀ ti o kún fun ọti kikan: nwọn si tẹ spunge bọ inu ọti kikan, nwọn fi i le ori ọpá hissopu, nwọn si fi i si i li ẹnu.

30 Nitorina nigbati Jesu si ti gbà ọti kikan na, o wipe, O pari: o si tẹ ori rẹ̀ ba, o jọwọ ẹmí rẹ̀ lọwọ.

31 Nigbana li awọn Ju bẹ̀ Pilatu pe, ki a le ṣẹ́ egungun itan wọn, ati ki a le gbé wọn kuro, nitoriti iṣe ipalẹmọ́, ki okú wọn ki o máṣe wà lori agbelebu li ọjọ isimi, (nitori ọjọ nla ni ọjọ isimi nì.)

32 Nigbana li awọn ọmọ-ogun de, nwọn si ṣẹ́ egungun itan ti ekini, ati ti ekeji, ti a kàn mọ agbelebu pẹlu rẹ̀.

33 Ṣugbọn nigbati nwọn de ọdọ Jesu, ti nwọn si ri pe, o ti kú na, nwọn kò si ṣẹ́ egungun itan rẹ̀:

34 Ṣugbọn ọkan ninu awọn ọmọ-ogun na fi ọ̀kọ gún u li ẹgbẹ, lojukanna ẹ̀jẹ ati omi si tú jade.

35 Ẹniti o ri i si jẹri, otitọ si li ẹrí rẹ̀: o si mọ̀ pe ōtọ li on wi, ki ẹnyin ki o le gbagbọ́.

36 Nitori a ṣe nkan wọnyi, ki Iwe mimọ́ ki o le ṣẹ, ti o wipe, A kì yio fọ́ egungun rẹ̀.

37 Iwe mimọ́ miran ẹ̀wẹ si wipe, Nwọn o ma wò ẹniti a gún li ọ̀kọ.

38 ¶ Lẹhin nkan wọnyi ni Josefu ará Arimatea, ẹniti iṣe ọmọ-ẹhin Jesu, ṣugbọn kì iṣe ni gbangba nitori ìbẹru awọn Ju, o bẹ̀ Pilatu ki on ki o le gbé okú Jesu kuro: Pilatu si fun u li aṣẹ. Nitorina li o wá, o si gbé okú Jesu lọ.

39 Nikodemu pẹlu si wá, ẹniti o tọ̀ Jesu wá loru niṣiwaju, o si mu ìdapọ ojia ati aloe wá, o to ìwọn ọgọrun litra li oṣuwọn.

40 Nigbana ni nwọn gbé okú Jesu, nwọn si fi aṣọ ọgbọ dì i pẹlu turari, gẹgẹ bi iṣe awọn Ju ti ri ni isinkú wọn.

41 Agbala kan si wà nibiti a gbé kàn a mọ agbelebu; iboji titun kan si wà ninu agbala na, ninu eyiti a ko ti itẹ́ ẹnikẹni si ri.

42 Ninu rẹ̀ ni nwọn si tẹ́ Jesu si, nitori ipalẹmọ́ awọn Ju; nitori iboji na sunmọ tosi.

## ORI 20.

LI ọjọ ikini ọ̀sẹ ni kutukutu nigbati ilẹ kò ti imọ́, ni Maria Magdalene wá si ibi iboji, o si ri pe, a ti gbé okuta kuro li ẹnu iboji.

2 Nigbana li o sare, o si tọ̀ Simoni Peteru wá, ati ọmọ-ẹhin miran, ẹniti Jesu fẹran, o si wi fun wọn pe, Nwọn ti gbé Oluwa kuro ninu iboji, awa kò si mọ̀ ibi ti nwọn gbé tẹ́ ẹ si.

3 Nigbana ni Peteru lọ, ati ọmọ-ẹhin miran na, nwọn si wá si ibi iboji.

4 Bẹ̄li awọn mejeji jùmọ sare: eyi ọmọ-ẹhin miran nì si sare yà Peteru kọja, o tètekọ de ibi iboji.

5 O bẹrẹ, nigbati o wò inu iboji, o ri aṣọ ọgbọ na lelẹ; ṣugbọn on kò wọ̀ inu rẹ̀.

6 Nigbana ni Simoni Peteru ẹniti ntọ̀ ọ lẹhin de, o wọ̀ inu iboji, o si ri aṣọ ọgbọ na lelẹ,

7 Ati gèle, ti o wà niha ori rẹ̀, kò si wà pẹlu aṣọ ọgbọ na, ṣugbọn a si ká a jọ li apakan fun ara rẹ̀.

8 Nigbana li ọmọ-ẹhin keji na, ẹniti o tètekọ de iboji wọ̀ inu rẹ̀ pẹlu, o ri, o si gbagbọ́.

Digitized by Google

9 Nitoripe titi fi di isisiyi, nwọn kò sá ti imọ̀ Iwe mimọ́ pe, on kò le ṣaima jinde kuro ninu okú.

10 Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin na si pada lọ sinu ile wọn.

11 ¶ Ṣugbọn Maria duro leti ibojì lode, o nsọkun: bi o ti nsọkun, o si bẹ̀rẹ, o wọ̀ inu ibojì.

12 O si ri awọn angeli meji alaṣọ funfun, nwọn joko, ọkan niha ori, ati ekeji niha ẹsẹ, nibiti okù Jesu gbé ti sùn.

13 Nwọn si wi fun u pe, Obirin yi, ẽṣe ti iwọ fi nsọkun? Ọ si wi fun wọn pe, Nitoriti nwọn ti gbé Oluwa mi lọ, emi kò si mọ̀ ibiti nwọn gbé tẹ́ ẹ si.

14 Nigbati o si ti wi bẽ tan, o yi ara rẹ̀ pada wò ẹhin, o si ri Jesu duro, on kò si mọ̀ pe Jesu ni.

15 Jesu wi fun u pe, Obirin yi, ẽṣe ti iwọ fi nsọkun? tani iwọ nwá? On ṣebi oluṣọgba ni iṣe, o wi fun u pe, Alàgba, bi iwọ ba ti gbé e kuro nihin, sọ ibiti o gbé tẹ́ ẹ si fun mi, emi o si gbé e kuro.

16 Jesu wi fun u pe, Maria. O si yi ara rẹ̀ pada, o wi fun u pe, Rabboni; eyi ti o jẹ Olukọni.

17 Jesu si wi fun u pe, Máṣe fi ọwọ́ kàn mi; nitoriti emi kò ti igòke lọ sọdọ Baba mi: ṣugbọn lọ sọdọ awọn arakọnrin mi, ki o si wi fun wọn pe, Emi gòke lọ sọdọ Baba mi, ati Baba nyin; ati sọdọ Ọlọrun mi, ati Ọlọrun nyin.

18 Maria Magdalene wa, o si wi fun awọn ọmọ-ẹhin pe, on ti ri Oluwa, ati pe, o si ti sọ nkan wọnyi fun on.

19 ¶ Li alẹ ijọ kanna, ti iṣe ijọ ikini ọ̀sẹ, nigbati gbogbo ilẹkun ti sé tan, nibiti awọn ọmọ-ẹhin gbé pejọ si, nitori ìbẹru awọn Ju, Jesu wọle, o duro larin wọn, o si wi fun wọn pe, Alafia fun nyin.

20 Nigbati o si ti wi bẽ tan, o fi ọwọ́ ati ìha rẹ̀ hàn wọn. Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin yọ̀, nigbati nwọn ri Oluwa.

21 Jesu si tún wi fun wọn pe, Alafia fun nyin: bi Baba mi ti rán mi, gẹgẹ bẽli emi rán nyin.

22 Nigbati o si ti wi eyi tan, o mí si wọn, o si wi fun wọn pe, Ẹ gbà Ẹmí Mimọ́:

23 Ẹ̀ṣẹ ẹnikẹni ti ẹnyin ba fi jì, a si fi jì wọn; ati ẹ̀ṣẹ ẹnikẹni ti ẹnyin ba si da duro, a si da wọn duro.

24 ¶ Ṣugbọn Tomasi, ọkan ninu awọn mejila, ti a npè ni Didimu, kò wà pẹlu wọn nigbati Jesu de.

25 Nitorina awọn ọmọ-ẹhin iyokù wi fun u pe, Awa ti ri Oluwa. Ṣugbọn o wi fun wọn pe, Bikoṣepe emi ba ri àpá iṣó li ọwọ́ rẹ̀, ki emi ki o si fi ika mi bọ àpá iṣó wọnni, ki emi ki o si tẹ̀ ọwọ́ mi bọ ìha rẹ̀, emi kì yio gbagbọ́.

26 ¶ Lẹhin ijọ mẹjọ awọn ọmọ-ẹhin si tún wà ninu ile, ati Tomasi pẹlu: nigbati gbogbo ilẹkun si ti sé tan, Jesu de, o si duro larin wọn, o si wipe, Alafia fun nyin.

27 Nigbana li o wi fun Tomasi pe, Mu ika rẹ wá nihin, ki o si wò ọwọ́ mi; si mu ọwọ́ rẹ wá nihin, ki o si tẹ̀ ẹ bọ ìha mi: ki iwọ ki o máṣe alaigbagbọ́ mọ́, ṣugbọn gbagbọ́.

28 Tomasi dahùn o si wi fun u pe, Oluwa mi ati Ọlọrun mi!

29 Jesu wi fun u pe, Tomasi, nitoriti iwọ ri mi ni iwọ fi gbagbọ́: alabukun-fun li awọn ti kò ti iri, ti nwọn si ti gbagbọ́.

30 ¶ Ati ọ̀pọlọpọ iṣẹ àmi miran ni Jesu ṣe nitõtọ niwaju awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, ti a kò kọ sinu iwe yi:

31 Ṣugbọn wọnyi li a kọ, ki ẹnyin ki o le gbagbọ́ pe, Jesu ni iṣe Kristi, Ọmọ Ọlọrun; ati pe gbigbà a gbọ́, ki ẹnyin ki o le ni ìye nipa orukọ rẹ̀.

## ORI 21.

LẸHIN nkan wọnyi, Jesu tún fi ara rẹ̀ hàn fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ leti adagun Tiberia; nipa bayi li o si fi ara rẹ̀ hàn fun wọn.

2 Simoni Peteru, ati Tomasi ti a npè ni Didimu, ati Natanaeli ara Kana ti Galili, ati awọn ọmọ Sebede, ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ meji miran jùmọ wà pọ̀.

3 Simoni Peteru wi fun wọn pe, Emi nlọ ipa ẹja. Nwọn wi fun u pe, Awa pẹlu mba ọ lọ. Bẽni nwọn jade, nwọn si wọ̀ inu ọkọ̀ kan lojukanna; li oru ijọ na nwọn kò si mu ohunkohun.

4 Ṣugbọn nigbati ilẹ mọ, Jesu duro leti adagun: ṣugbọn awọn ọmọ-ẹhin kò mọ̀ pe, Jesu ni.

5 Nigbana ni Jesu wi fun wọn pe, Ẹnyin ọmọde, ẹ li onjẹ diẹ? Nwọn da a lohùn wipe, Awa kò ni.

6 O si wi fun wọn pe, Ẹ sọ àwọn si apa ọtún ọkọ̀, ẹnyin o si ri. Nigbana ni nwọn sọ àwọn sibẹ̀, nwọn kò si le fà a jade nitori ọ̀pọlọpọ ẹja.

7 Nitorina li ọmọ-ẹhin na ti Jesu fẹran wi fun Peteru pe, Oluwa ni. Nigbati Simoni Peteru ti gbọ́ pe, Oluwa ni, o si di amure ẹ̀wu apẹja rẹ̀ mọra, (nitoripe o wà ni ìhoho,) o si gbé ara rẹ̀ sọ sinu adagun.

8 Awọn ọmọ-ẹhin miran si ti inu ọkọ̀ kekere kan wá; (nitoriti nwọn kò jina silẹ̀, ṣugbọn bi iwọn igba igbọnwọ,) nwọn nwọ́ àwọn na ti on ti ẹja.

9 Nigbati nwọn si ti gúnlẹ, nwọn ri iná ẹyín nibẹ̀, a si fi ẹja le ori rẹ̀ ati akara.

10 Jesu wi fun wọn pe, Ẹ kó diẹ ninu ẹja ti ẹnyin pa nisisiyi wá.

11 Simoni Peteru gòke lọ, o si fà àwọn na wálẹ, o kún fun ẹja nla, o jẹ mẹtalelãdọjọ: ṣugbọn bi nwọn ti pọ̀ to nì, àwọn na kò si fàya.

12 Jesu wi fun wọn pe, Ẹ wá jẹun owurọ̀. Kò si si ẹnikan ninu awọn ọmọ-ẹhin ti o jẹ bi i pe, Iwọ tani? nitoriti nwọn mọ̀ pe Oluwa ni.

13 Nigbana ni Jesu wá, o mu akara, o si fifun wọn, gẹgẹ bẹ̃ si li ẹja.

14 Eyi li o di igba kẹta nisisiyi ti Jesu fi ara rẹ̀ hàn fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, lẹhin igbati o jinde kuro ninu okú.

15 ¶ Lẹhin igbati nwọn jẹun owurọ̀ tan, Jesu wi fun Simoni Peteru pe, Simoni, ọmọ Jona, iwọ fẹràn mi jù awọn wọnyi lọ? O si wi fun u pe, Bẹ̃ni Oluwa; iwọ mọ̀ pe, mo fẹràn rẹ. O si wi fun u pe, Mã bọ́ awọn ọdọ agutan mi.

16 O si tún wi fun u nigba keji pe, Simoni, ọmọ Jona, iwọ fẹràn mi? O si wi fun u pe Bẹ̃ni Oluwa; iwọ mọ̀ pe, mo fẹràn rẹ. O si wi fun u pe, Mã bọ́ awọn agutan mi.

17 O si tún wi fun u nigba kẹta pe, Simoni, ọmọ Jona, iwọ fẹràn mi? Inu Peteru bajẹ, nitoriti o wi fun u nigba ẹkẹta pe, Iwọ fẹràn mi? O si wi fun u pe, Oluwa, iwọ mọ̀ ohun gbogbo; iwọ mọ̀ pe, mo fẹràn rẹ. Jesu wi fun u pe, Mã bọ́ awọn agutan mi.

18 Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun ọ, nigbati iwọ ṣe ọdọmọde, iwọ ama di ara rẹ li amure, iwọ a si ma lọ si ibiti iwọ fẹ: ṣugbọn nigbati iwọ ba gbó tan, iwọ o si nà ọwọ́ rẹ siwaju, ẹlomiran yio si di ọ li amure, yio si fà ọ lọ si ibiti iwọ kò fẹ.

19 O wi eyi, o fi nṣapẹrẹ irú ikú ti yio fi yìn Ọlọrun logo. Lẹhin igbati o si ti wi eyi tan, o wi fun u pe, Mã tọ̀ mi lẹhin.

20 Peteru si yipada, o ri ọmọ-ẹhin nì, ẹniti Jesu fẹràn, mbọ̀ lẹhin; ẹniti o fi ori tì i li àiya nigba onjẹ alẹ ti o si wi fun u pe, Oluwa, tali ẹniti o fi ọ hàn?

21 Nigbati Peteru ri i, o wi fun Jesu pe, Oluwa, kili eleyi yio ha ṣe?

22 Jesu wi fun u pe, Bi emi ba fẹ pe, ki o duro titi emi o fi de, kili eyini si ọ? iwọ mã tọ̀ mi lẹhin.

23 Ọ̀rọ yi si tàn kalẹ kiri ninu awọn arakọnrin pe, ọmọ-ẹhin nì kì yio ku: ṣugbọn Jesu kò wi fun u pe, On kì yio kú; ṣugbọn, Bi emi ba fẹ pe, ki o duro titi emi o fi de, kili eyinì si ọ?

24 Eyi si li ọmọ-ẹhin na, ẹniti o jẹri nkan wọnyi, ti o si kọwe nkan wọnyi: awa si mọ̀ pe, otitọ li ẹrí rẹ̀.

25 Ati ọ̀pọlọpọ ohun miran pẹlu ni Jesu ṣe, eyiti bi a ba kọwe gbogbo wọn, mo rò pe aiye pãpã kò le gbà iwe na ti a ba kọ. Amin.

# IṢE AWỌN APOSTELI.

## ORI 1.

TEOFILU ìhìn iṣaju ni mo ti rò, niti gbogbo ohun ti Jesu bẹ̀rẹ si iṣe, ati si ikọ́,

2 Titi o fi di ọjọ ti a gbé e lọ soke, lẹhin igbati o ti ti ipa Ẹmi Mimọ́ paṣẹ, fun awọn aposteli, ti o ti yàn:

3 Ẹniti o si fi ara rẹ̀ hàn fun lãye lẹhin ìjiya rẹ̀ nipa ẹrí pipọ dajudaju, ẹniti a ri lọdọ wọn li ogoji ọjọ, ti o nsọ ohun ti iṣe ti ijọba Ọlọrun?

4 Nigbati o si ba wọn pejọ, o paṣẹ fun wọn pe, ki nwọn ki o máṣe jade kuro ni Jerusalemu, ṣugbọn ki nwọn ki o duro dè ileri Baba, ti o ni, ẹnyin ti gbọ́ li ẹnu mi.

5 Nitõtọ ni Johannu fi omi baptisi; ṣugbọn a o fi Ẹmí Mimọ́ baptisi nyin ki iṣe ọjọ pipọ lati oni lọ.

6 Nigbati nwọn si pejọ, nwọn bère lọdọ

Digitized by Google

rẹ̀ pe, Oluwa, lati igbayi lọ, iwọ o ha mu
ijọba pada fun Israeli?
7 O si wi fun wọn pe, Kì iṣe ti nyin lati
mọ̀ igba tabi akokò, ti Baba fi si agbara
ọwọ ara rẹ̀.
8 Ṣugbọn ẹnyin o gbà agbara, lẹhìn ti
Ẹmí Mimọ́ ba bà le nyin: ẹnyin o si ma
ṣe ẹlẹri mi ni Jerusalemu, ati ni gbogbo
Judea, ati ni Samaria, ati titi yio fi de opin
ilẹ aiye.
9 Nigbati o si ti wi nkan wọnyi, bi nwọn
ti nwò o, a gbé e soke; awọsanma si gbà a
kuro li oju wọn.
10 Bi nwọn si ti tẹ̀ oju mọ́ oju ọrun
nigbati o nrè oke, kiyesi i, awọn ọkọnrin
meji alaṣọ àla duro leti ọdọ wọn;
11 Ti nwọn si wipe, Ẹnyin ọkọnrin ará
Galili, ẽṣe ti ẹnyin fi duro ti ẹnyin ntẹ̀ oju
mọ́ oju ọrun? Jesu na yi, ti a gbà soke
ọrun kuro lọwọ nyin, yio si tún pada wá
gẹgẹ bi ẹnyin ti ri i ti o nlọ si ọrun.
12 Nigbana ni nwọn si pada ti òke ti a
npè ni Olifi lọ si Jerusalemu, ti o jina si
Jerusalemu ni ìwọn ìrin ọjọ isimi kan:
13 Nigbati nwọn si wọle, nwọn lọ si
yara oke, nibiti Peteru gbé wà, ati Jakọbu,
ati Johannu, ati Anderu, ati Filippi, ati
Tomasi, Bartolomeu, ati Matteu, Jakọbu
ọmọ Alfeu, ati Simoni Selote, ati Juda ara-
kọnrin Jakọbu.
14 Gbogbo awọn wọnyi fi ọkàn kan
duro si adura ati si ẹ̀bẹ, pẹlu awọn obirin,
ati Maria iya Jesu pẹlu awọn arakọnrin
rẹ̀.
15 ¶ Ni ijọ wọnni ni Peteru si dide
duro li awujọ awọn ọmọ-ẹhin (iye oru-
kọ awọn enia gbogbo ninu ijọ jẹ ọgọfa,)
o ni,
16 Ẹnyin alàgba ati arakọnrin, Iwe mi-
mọ́ yi kò le ṣe ki o ma ṣẹ, ti Ẹmí Mimọ́ ti
sọtẹlẹ li ẹnu Dafidi nipa ti Judasi, ti o ṣe
amọ̀na fun awọn ti o mu Jesu.
17 Nitoriti a kà a kún wa, o si ni ipà
ninu iṣẹ iranṣẹ yi.
18 Njẹ ọkọnrin yi sá ti fi ère ẹ̀ṣẹ rà ilẹ
kan; nigbati o ṣubu li ogedengbe, o bẹ́ li
agbedemeji, gbogbo ifun rẹ̀ si tú jade.
19 A si gbọ́ ìhin na kalẹ lọdọ gbogbo
awọn ara Jerusalemu; nitorina li a fi npè
igbẹ́ na ni Akeldama li ède wọn, eyini ni,
Igbẹ́ ẹ̀jẹ.
20 A sá kọ ọ ninu Iwe Psalmu pe, Ki
ibujoko rẹ̀ ki o di ahoro, ki ẹnikan ki o
máṣe gbé ibẹ̀ mọ́: ati oyè rẹ̀ ni ki ẹlomiran
gbà.
21 Njẹ o yẹ, ninu awọn ọkọnrin wọnyi
ti nwọn ti mba wa rìn ni gbogbo akoko
ti Jesu Oluwa fi nwọle, ti o si njade lãrin
wa,
22 Bẹrẹ lati igba baptismu Johannu wá,
titi o fi di ọjọ na ti a gbé e lọ soke kuro
lọdọ wa, ki awa ki o yàn ọkan ṣe ẹlẹri
ajinde rẹ̀ pẹlu wa.
23 Nwọn si yàn awọn meji, Josefu ti a
npè ni Barsabba, ti nwọn si sọ apele rẹ̀ ni
Justu, ati Mattia.
24 Nwọn si gbadura, nwọn si ni, Iwọ,
Oluwa, ti o mọ̀ ọkàn enia gbogbo, fihàn
ninu awọn mejeji yi, ewo ni iwọ yàn,
25 Ki o le gbà apakan ni iṣẹ iranṣẹ, ati
ni iṣẹ aposteli yi, ninu eyiti Judasi ti fi ẹṣẹ
ṣubu, ki o le lọ si ipò tirẹ̀.
26 Nwọn si di ìbo wọn; ìbo si mu
Mattia; a si kà a kún awọn aposteli mọ-
kanla iyokù.

## ORI 2.

NIGBATI ọjọ Pentekosti si pé tan, gbo-
gbo nwọn fi ọkàn kan wà nibikan.
2 Lojijì iró si ti ọrun wá, gẹgẹ bi iró
ẹfufu lile, o si kún gbogbo ile nibiti nwọn
gbé joko.
3 Ẹla ahọn bi ti iná si yọ si wọn, o si
bà le olukuluku wọn.
4 Gbogbo wọn si kún fun Ẹmí Mimọ́,
nwọn si bẹrẹ si ifi ède miran fọ̀, gẹgẹ bi
Ẹmí ti fun wọn li ohùn.
5 Awọn Ju enia rere si wà ti nṣe atipo
ni Jerusalemu, lati orilẹ-ède gbogbo wá ti
mbẹ labẹ ọrun.
6 Nigbati a si ti ròhin eyi yiká, ọ̀pọlọpọ
enia pejọ, nwọn si damu, nitoriti oluku-
luku gbọ́ nwọn nsọ̀rọ li ède rẹ̀.
7 Hà si ṣe gbogbo wọn, ẹnu si yà wọn,
nwọn nwi fun ara wọn pe, Kiyesi i, gbo-
gbo awọn wọnyi ti nsọ̀rọ, ara Galili ki
nwọn iṣe?
8 Ẽha si ti ṣe ti olukuluku enia fi ngbọ́
li ède wa, nibiti a gbé bí wa?
9 Ara Partia, ati ara Media, ati ara
Elamu, ati awọn ti ngbé Mesopotamia, ati
ni Judea, ati Kappadokia, ni Pontu, ati
Asia,
10 Frigia ati Pamfilia, ni Egipti, ati li
apa ìha Libia niha Kirene, ati awọn atipo
ara Romu, awọn Ju ati awọn alawọṣe Ju,
11 Ara Krete ati awọn ara Arabia, awa
gbọ́ nwọn nsọ̀rọ iṣẹ iyanu nla Ọlọrun li ède
wa.
12 Hà si ṣe gbogbo wọn, nwọn si wà ni
iyemeji, nwọn mbi ara wọn pe, Kili a le
mọ̀ eyi si?

Digitized by Google

13 Awọn ẹlomiran nṣẹfẹ wipe, Awọn
ọkọnrin wọnyi kún fun ọti-waini titun.
14 ¶ Ṣugbọn nigbati Peteru dide duro
pẹlu awọn mọkanla iyokù, o gbé ohùn rẹ̀
soke, o si sọ fun wọn pe, Ẹnyin ọkọnrin
Judea, ati gbogbo ẹnyin ti ngbé Jerusa-
lemu, ki eyiyi ki o yé nyin, ki ẹnyin ki o
si fi etí si ọ̀rọ mi:
15 Nitori awọn wọnyi kò mọtiyó, bi
ẹnyin ti fi pè, wakati kẹta ọjọ sá li eyi.
16 Ṣugbọn eyi li ọ̀rọ̀ ti a ti sọ lati ẹnu
woli Joeli wá pe;
17 Ọlọrun wipe, Yio si ṣe ni ikẹhin ọjọ,
Emi o tú jade ninu Ẹmí mi si ara enia
gbogbo: ati awọn ọmọ nyin ọkọnrin ati
awọn ọmọ nyin obirin yio ma sọtẹlẹ, ati
awọn ọdọmọkọnrin nyin yio ma riran, ati
awọn arugbo nyin yio ma lá alá:
18 Ati lara awọn ọmọ-ọdọ mi ọkọnrin,
ati lara awọn ọmọ-ọdọ mi obirin li emi o tú
ninu Ẹmí mi si li ọjọ wọnni; nwọn o si
mã sọtẹlẹ:
19 Emi o si fi iṣẹ iyanu hàn loke ọrun,
ati àmi nisalẹ ilẹ; ẹ̀jẹ, ati iná, ati riru
ẽfin:
20 A o sọ õrùn di òkunkun, ati oṣupa
di ẹ̀jẹ, ki ọjọ nla afiyesi Oluwa ki o to
de:
21 Yio si ṣe, ẹnikẹni ti o ba pè orukọ
Oluwa, a o gbà a là.
22 Ẹnyin ọkọnrin Israeli, ẹ gbọ́ ọ̀rọ
wọnyi: Jesu ti Nasareti, ọkọnrin ti a fi iṣẹ
aṣẹ ati ti iyanu, ati àmi tẹwọgbà lọdọ Ọlọ-
run ninu nyin, ti Ọlọrun ti ọwọ́ rẹ̀ ṣe li
awujọ nyin, bi ẹnyin tikara nyin ti mọ̀
pẹlu:
23 Ẹniti a ti fi ipinnu ìmọ ati amọtẹlẹ
Ọlọrun jọwọ rẹ̀ lọwọ, ẹnyin mu u, ẹnyin si
ti fi ọwọ́ ẹ̀ṣẹ kàn a mọ agbelebu, ẹnyin si
pa a:
24 Ẹniti Ọlọrun ti gbé dide, ti o ti tú
irora ikú: nitoriti kò le ṣe ti a o ti ọdọ rẹ̀
dì i mu.
25 Nitori Dafidi ti wi nipa tirẹ̀ pe, Mo
ri Oluwa nigbagbogbo niwaju mi, nitoriti
o mbẹ li ọwọ́ ọtún mi, ki a máṣe le ṣí mi
ni ipò:
26 Nitorina ni inu mi dùn, ahọn mi si
yọ̀; ati pẹlu-pẹlu ara mi yio simi ni ireti:
27 Nitoriti iwọ ki yio fi ọkàn mi silẹ ni
ipò okú, bẽni iwọ ki yio jẹ ki Ẹni-Mimọ́ rẹ
ki o dibajẹ.
28 Iwọ ti fi ọ̀na ìye hàn fun mi; iwọ o
si fi ayọ̀ iwaju rẹ kún mi.
29 Alàgba, ará, ẹ jẹ ki emi ki o sọ fun
nyin nigbangba niti Dafidi Baba nla pe, o
kú, a si sin i pẹlu, iboji rẹ̀ si mbẹ lọdọ wa
titi o fi di oni yi.
30 Nitoriti iṣe woli, o si ti mọ̀ pe, Ọlọ-
run ti fi èpe bura fun u pe, ninu irú-ọmọ
inu rẹ̀ nipa ti ara, on o mu Kristi wá ijoko
lori itẹ́ rẹ̀;
31 O ri eyi tẹlẹ, o sọ ti ajinde Kristi pe,
a kò fi ọkàn rẹ̀ silẹ ni ipò okú, bẹ̀li ara rẹ̀
kò si dibajẹ.
32 Jesu na li Ọlọrun ti jinde, ẹlẹri ẹniti
gbogbo wa nṣe.
33 Nitorina ẹniti a ti fi ọwọ́ ọtún Ọlọ-
run gbéga, ti o si ti gbà ileri Ẹmí Mimọ́
lọdọ Baba, o dà eyi silẹ, ti ẹnyin si nri, ti
ẹnyin ngbọ́ nisisiyi.
34 Dafidi kò sá gòke lọ si ọrun: ṣugbọn
on tikararẹ̀ wipe, Oluwa wi fun Oluwa mi
pe, Iwọ joko li ọwọ́ ọtún mi,
35 Titi emi o fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti
itisẹ rẹ.
36 Njẹ ki gbogbo ará ile Israeli ki o mọ̀
dajudaju pe, Ọlọrun ti fi Jesu na, ti ẹnyin
kàn mọ agbelebu, jẹ Oluwa ati Kristi.
37 ¶ Nigbati nwọn si gbọ́ bayi, àiya
gún wọn ṣin, nwọn si bi Peteru ati awọn
aposteli iyokù pe, Alàgba, ará, kini ki awa
ki o ṣe?
38 Peteru si wi fun wọn pe, Ẹ ronupi-
wada, ki a si baptisi olukuluku nyin li
orukọ Jesu Kristi nitori idariji ẹ̀ṣẹ, ẹnyin
o si gbà ẹ̀bun Ẹmi Mimọ́.
39 Nitori ileri yi ni fun nyin, ati fun
awọn ọmọ nyin, ati fun gbogbo awọn ti o
jìna rére, ati fun iye awọn ti Oluwa Ọlọrun
wa o pè.
40 Ati pẹlu ọ̀rọ miran pipọ li o fi nsọ ti
o si fi nkìlọ wipe, Ẹ gbà ara nyin là lọwọ
iran arekereke yi.
41 ¶ Awọn ti o si fi ayọ̀ gbà ọ̀rọ rẹ̀ a
baptisi wọn: li ọjọ na a kà ìwọn ẹgbẹdo-
gun ọkàn kún wọn.
42 Nwọn si duro ṣinṣin ninu ẹkọ́ ati
ìdapọ awọn aposteli, ati ni ibu akara ati
ninu adura.
43 Ẹru si ba gbogbo ọkàn: iṣẹ iyanu
ati iṣẹ àmi pipọ li a ti ọwọ́ awọn aposteli
ṣe.
44 Gbogbo awọn ti o si gbagbọ́ wà nibi
kan, nwọn ni nkan gbogbo ṣọkan;
45 Nwọn si tà ọrọ̀ ati ọjà wọn, nwọn si
pín wọn fun gbogbo awọn enia, bi oluku-
luku ti ṣe alaini si.
46 Nwọn si fi ọkàn kan duro li ojojumọ́
ni tempili ati ni ibu akara lati ile de ile,
nwọn nfi inu didùn ati ọkàn kan jẹ onjẹ
wọn.

Digitized by Google

47 Nwọn nyìn Ọlọrun, nwọn si ni oju rere lọdọ enia gbogbo. Oluwa si nyàn kún ijọ enia na li ojujumọ́, irú awọn ti a o gbalà.

## ORI 3.

NJẸ Peteru on Johannu jumọ ngòke lọ si tempili li akokò wakati adura, o jẹ wakati kẹsan ọjọ.
2 Nwọn gbé ọkọnrin kan, ti o yarọ lati inu iya rẹ̀ wá, ti nwọn ima gbé kalẹ li ojojumọ́ li oju-ọ̀na tempili ti a npè ni Daradara, lati mã ṣagbe lọwọ awọn ti nwọ̀ inu tempili lọ;
3 Ẹniti o ri Peteru on Johannu bi nwọn ti nwọ̀ inu tempili, o ṣagbe.
4 Nigbati Peteru tẹjumọ́ ọ pẹlu Johannu, o ni, Wò wa.
5 O si fi oju si wọn, o nreti ati ri nkan gbà lọwọ wọn.
6 Nigbana ni Peteru wi fun u pe, Fadakà ati wura emi kò ni; ṣugbọn irú ohun ti mo ni mo fifun ọ: Li orukọ Jesu Kristi ti Nasareti dide ki o si mã rìn.
7 O si fà a li ọwọ́ ọtún, o si gbé e dide: li ojukanna ẹsẹ rẹ̀ ati egungun kokosẹ rẹ̀ mu okun.
8 O si nfò soke, o duro, o si rìn, o si ba wọn wọ̀ inu tempili lọ, o nrìn, o nfò, o si nyìn Ọlọrun.
9 Gbogbo awọn enia si ri i, o nrìn, o si nyìn Ọlọrun:
10 Nwọn si mọ̀ pe on li o ti joko nṣagbe li oju-ọ̀na Daradara ti tempili: hà si ṣe wọn, ẹnu si yà wọn gidigidi si ohun ti o ṣẹ lara rẹ̀.
11 Bi ọkọnrin arọ ti a mu lara da ti dì Peteru on Johannu mu, gbogbo awọn enia sure jọ tọ̀ wọn lọ ni iloro ti a npè ni ti Solomoni, ẹnu yà wọn gidigidi.
12 ¶ Nigbati Peteru si ri i, o dahùn wi fun awọn enia pe, Ẹnyin ọkọnrin Israeli, ẽṣe ti hà fi nṣe nyin si eyi? tabi ẽṣe ti ẹnyin fi tẹjumọ́ wa, bi ẹnipe agbara tabi mimọ́-iwa wa li awa fi ṣe ti ọkọnrin yi fi nrìn?
13 Ọlọrun Abrahamu, ati ti Isaaki, ati ti Jakọbu, Ọlọrun awọn baba wa, on li o ti yìn Jesu Ọmọ rẹ̀ logo; ẹniti ẹnyin ti fi le wọn lọwọ, ti ẹnyin si sẹ́ niwaju Pilatu, nigbati o ti pinnu rẹ̀ lati jọwọ rẹ̀ lọwọ.
14 Ṣugbọn ẹnyin sẹ́ Ẹni-Mimọ́ ati Olõtọ nì, ẹnyin si fẹ ki a fi apani fun nyin;
15 Ẹnyin si pa Olupilẹṣẹ ìye, ti Ọlọrun si ti jinde kuro ninu okú; ẹlẹri ohun ti awa nṣe yi.
16 Nipa igbagbọ́ li orukọ rẹ̀ on li o mu ọkọnrin yi lara le, ẹniti ẹnyin ri ati ti ẹnyin si mọ̀: ati igbagbọ́ nipa tirẹ̀ on li o fun u ni dada ara ṣaṣa yi li oju gbogbo nyin.
17 Njẹ nisisiyi, ará, emi mọ̀ pe, nipa aimọ̀ li ẹnyin fi ṣe e, ati awọn olori nyin pẹlu.
18 Ṣugbọn gbogbo nkan wọnni, ti Ọlọrun ti fihàn tẹlẹ lati ẹnu gbogbo awọn woli rẹ̀ wá pe, Kristi yio jiya, on li o mu ṣẹ bẹ̃.
19 ¶ Njẹ ẹ ronupiwada, ki ẹ si yipada, ki a le pa ẹ̀ṣẹ nyin rẹ́, nigbati itura yio ba ti iwaju Oluwa de;
20 On o si rán Jesu Kristi, ti a ti wasu fun nyin tẹlẹ:
21 Ẹniti ọrun kò le ṣaima gbà titi yio fi di igba amupada ohun gbogbo, ti Ọlọrun ti sọ li ẹnu gbogbo awọn woli rẹ̀ mimọ́ lati igba ọjọ ìwa.
22 Mose sá ti sọ fun awọn baba nitõtọ pe, Oluwa Ọlọrun nyin yio gbé woli kan dide fun nyin ninu awọn arakọnrin nyin, bi emi; on ni ki ẹnyin ki o ma gbagbọ́ li ohun gbogbo ti yio ma sọ fun nyin.
23 Yio si ṣe, olukuluku ọkàn ti kò ba gbà woli na gbọ́, on li a o parun kuro ninu awọn enia.
24 Bẹ̃ni, ati gbogbo awọn woli lati Samueli wá, ati gbogbo awọn ti o hù lẹhin rẹ̀, iye awọn ti o ti sọ, awọn si ti sọ̀rọ ọjọ wọnyi tẹlẹ pẹlu.
25 Ẹnyin li ọmọ awọn woli, ati majẹmu ti Ọlọrun ti da fun awọn Baba wa, o nwi fun Abrahamu pe, Ati ninu irú-ọmọ rẹ li a o ti fi ibukun fun gbogbo ibatan araiye.
26 Nigbati Ọlọrun jí Jesu Ọmọ rẹ̀ dide, o tète rán a si nyin lati busi i fun nyin, ati lati yi olukuluku nyin pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀.

## ORI 4.

BI nwọn si ti mba awọn enia sọrọ, awọn alufa, ati olori ẹ̀ṣọ́ tempili ati awọn Sadusi dide si wọn,
2 Inu wọn bajẹ, nitoriti nwọn nkọ́ awọn enia, ati ti nwọn si nfi Jesu wasu ajinde kuro ninu okú.
3 Nwọn si nawọ́ mu wọn, nwọn há wọn mọ́ ile tubu titi o fi di ijọ keji: nitoriti alẹ lẹ tan.
4 Ṣugbọn ọ̀pọ awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ na gbagbọ́; iye wọn si to ẹgbẹdọgbọn ọkọnrin.
5 ¶ O si ṣe nijọ keji, awọn olori wọn, ati awọn alàgba, ati awọn akọwe, pejọ si Jerusalemu,

Digitized by Google

6 Ati Anna olori alufa, ati Kaiafa, ati
Johannu, ati Aleksanderu, ati ìwọn awọn
ti iṣe ibatan olori alufa.
7 Nigbati nwọn si mu wọn duro li ãrin,
nwọn bère pe, Agbara, tabi orukọ wo li
ẹnyin fi ṣe eyi?
8 Nigbana ni Peteru kún fun Ẹmí Mimọ́,
o wi fun wọn pe, Ẹnyin olori awọn enia,
ati alàgba Israeli,
9 Bi o ba ṣepe a nwadi wa niti iṣẹ rere
ti a ṣe si ọkọnrin abirùn na, li ọna ti a fi
mu u lara da;
10 Ki eyiyi ki o yé gbogbo nyin ati
gbogbo enia Israeli pe, li Orukọ Jesu Kristi
ti Nasareti, ti ẹnyin kàn mọ agbelebu, ti
Ọlọrun si gbé dide kuro ninu okú, nipa rẹ̀
li ọkọnrin yi fi duro niwaju nyin nisisiyi
ni dida ara ṣaṣa.
11 Eyiyi li okuta ti a ti ọwọ́ ẹnyin ọmọle
kọ̀ silẹ, ti o si di pàtaki igun ile.
12 Bẹ̃ni kò si si igbala lọdọ ẹlomiran:
nitori kò si orukọ miran labẹ ọrun ti a fi
fun ni ninu enia, ti a o fi gbà wa là.
13 ¶ Nigbati nwọn si ri igboiya Peteru
on Johannu, ti nwọn si wò pe, nwọn ṣe
alaikọ́ nkan ati òpe enia, ẹnu yà wọn;
nwọn si woye wọn pe, nwọn a ti ma ba
Jesu gbé.
14 Nigbati nwọn si nwò ọkọnrin na ti a
mu larada, ti o ba wọn duro, nwọn kò le
ri nkan wi si i.
15 Nigbati nwọn si rán wọn jade kuro
li awujọ, nwọn ba ara wọn gbìro.
16 Wipe, Kili awa o ṣe awọn ọkọnrin
wọnyi? ti pe iṣẹ aṣẹ nla ti ọwọ́ wọn ṣe, o
hàn gbangba fun gbogbo awọn ti ngbé
Jerusalemu; awa kò si le sẹ́ ẹ.
17 Ṣugbọn ki o màṣe le tàn kalẹ siwaju
mọ́ lọdọ awọn enia, ẹ jẹ ki a kìlọ fun wọn
gidigidi pe, lati isisiyi lọ ki nwọn ki o
máṣe fi orukọ yi sọ̀rọ fun ẹnikẹni mọ́.
18 Nigbati nwọn si pè wọn, nwọn kìlọ
fun wọn, ki nwọn máṣe sọ̀rọ rara, tabi ki
nwọn má kọ́ni li orukọ Jesu mọ́.
19 Ṣugbọn Peteru on Johannu dahùn,
nwọn si wi fun wọn pe, Bi o ba tọ́ li oju
Ọlọrun lati gbọ́ ti nyin jù ti Ọlọrun lọ, ẹ
gbà a rò.
20 Awa kò sá le ṣaima sọ ohun ti awa ti
ri, ti a si ti gbọ́.
21 Nigbati nwọn si kìlọ fun wọn si i,
nwọn jọwọ wọn lọwọ lọ, nigbati nwọn kò
ti ri nkan ti nwọn iba fi jẹ wọn ni ìya,
nitori awọn enia: nitori gbogbo enia ni
nyìn Ọlọrun logo fun ohun ti o ṣe.
22 Nitori ọkọnrin na jù ẹni-ogoji ọdún
lọ, lara ẹniti a gbé fi iṣẹ aṣẹ dida ara yi
hàn.
23 ¶ Nigbati nwọn si jọwọ wọn lọwọ
lọ, nwọn lọ sọdọ awọn ẹgbẹ wọn, nwọn si
ròhin ohun gbogbo ti awọn olori alufa ati
awọn alàgba sọ fun wọn.
24 Nigbati nwọn si gbọ́ eyini, nwọn fi
ọkàn kan gbé ohùn wọn soke si Ọlọrun pe,
Oluwa, iwọ li Ọlọrun, ti o da ọrun on aiye,
ati okun, ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu
wọn:
25 Ẹniti o ti ẹnu Dafidi ọmọ-ọdọ rẹ̀ wi
pe, Ẽṣe ti awọn keferi fi mbinu, ati ti awọn
enia ngbìro ohun asan?
26 Awọn ọba aiye dide duro, ati awọn
olori kó ara wọn jọ si Oluwa, ati si Kristi
rẹ̀.
27 Nitõtọ sá ni, si Jesu Ọmọ mimọ́ rẹ,
ẹniti iwọ ti fi àmi oróro yàn, ni ati Herodu,
ati Pontiu Pilatu, pẹlu awọn Keferi, ati
awọn enia Israeli pejọ si,
28 Lati ṣe ohunkohun ti ọwọ́ rẹ ati ìmọ
rẹ ti pinnu ṣaju lati ṣe.
29 Njẹ nisisiyi, Oluwa, kiyesi ìlọ wọn:
ki o si fifun awọn ọmọ-ọdọ rẹ, lati ma fi
igboiya gbogbo sọ ọ̀rọ rẹ.
30 Nipa ifi ninà ọwọ́ rẹ ṣe dida ara; ati
ki iṣẹ àmi ati iṣẹ iyanu ki o mã ṣe li orukọ
Jesu Ọmọ mimọ́ rẹ.
31 ¶ Nigbati nwọn gbadura tan, ile ti
nwọn gbé pejọ si mì-titi; gbogbo wọn si
kún fun Ẹmí Mimọ́, nwọn si fi igboiya sọ
ọ̀rọ Ọlọrun.
32 Ijọ enia ti o gbagbọ́ si wà li àiya ati
ọkàn kan: kò si si ẹniti o ni nkankan ti o
pè ni ti ara rẹ̀; ṣugbọn gbogbo nwọn ni
nkan ṣọkan.
33 Agbara nla li awọn aposteli si fi jẹri
ajinde Jesu Oluwa; ore-ọfẹ pipọ si wà ninu
gbogbo wọn.
34 Kò si si ẹnikan ninu wọn ti o ṣe
alaini: nitori iye awọn ti o ni ilẹ tabi ile
tà wọn, nwọn mu owo ohun ti nwọn tà
wá,
35 Nwọn si fi i lelẹ li ẹsẹ awọn aposteli:
nwọn si ṣe ipín rẹ̀ fun olukuluku, gẹgẹ bi
o ti ṣe alaini si.
36 Ati Jose, ti a ti ọwọ awọn aposteli sọ
ni Barnaba, (ni itumọ̀ eyi ti ijẹ Ọmọ-
Itùnu) ti ẹ̀ya Lefi, ati ara Kipru,
37 O ni ilẹ kan, o tà a, o si mu owo rẹ̀
wá, o fi i lelẹ li ẹsẹ awọn aposteli.

## ORI 5.

ṢUGBỌN ọkọnrin kan ti a npè ni Anania,
pẹlu Safira aya rẹ̀, nwọn tà ilẹ iní kan.

Digitized by Google

2 O si yàn apakan pamọ́ ninu owo na, aya rẹ̀ ba a ṣe imùlẹ rẹ̀ pẹlu, o si mu apakan rẹ̀ wá, o si fi i lelẹ li ẹsẹ awọn aposteli.

3 Ṣugbọn Peteru wipe, Anania, Ẽṣe ti Satani fi kún ọ li àiya lati ṣeke si Ẹmí Mimọ́, ti iwọ si fi yàn apakan pamọ́ ninu owo ilẹ na.

4 Nigbati o wà li ọwọ́ rẹ, tirẹ ki iṣe? lẹhin igbati a si tà a tan, kò ha wà li ọwọ́ ara rẹ? Ẽha ti ṣe ti iwọ fi rò kini yi li ọkàn rẹ? ṣugbọn enia ki iwọ ṣeke si bikoṣe si Ọlọrun.

5 Nigbati Anania si gbọ́ ọ̀rọ wọnyi, o ṣubu lulẹ, o si kú: ẹ̀ru nla si ba gbogbo awọn ti o gbọ́ nkan wọnyi.

6 Awọn ọmọkọnrin si dide, nwọn dì i, nwọn si gbé e jade, nwọn si sin i.

7 O si to ìwọn ọ̀sa wakati mẹta lẹhin eyi, aya rẹ̀ ti kò mọ̀ ohun ti o ti ṣe, o wọle.

8 Peteru si dahùn o bi i pe, Wi fun mi, bi ni iye bayi li ẹnyin tà ilẹ na? O si wipe, Lõtọ iye bẽni.

9 Peteru si wi fun u pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi mulẹ pọ̀ lati dán Ẹmí Oluwa wò? wò o, ẹsẹ awọn ti o sinkú ọkọ rẹ mbẹ li ẹnu-ọ̀na, nwọn o si gbé ọ jade.

10 O si ṣubu lulẹ li ẹsẹ rẹ̀ lojukanna, o si kú: awọn ọmọkọnrin si wọle, nwọn bá a o kú, nwọn si gbé e jade, nwọn sin i lẹba ọkọ rẹ̀.

11 Ẹru nla si ba gbogbo ijọ, ati gbogbo ìwọn awọn ti nwọn gbọ́ nkan wọnyi.

12 ¶ A si ti ti ọwọ́ awọn aposteli ṣe iṣẹ àmi ati iṣẹ iyanu pipọ ninu awọn enia; gbogbo wọn si fi ọkàn kan wà ni iloro Solomoni.

13 Ati ninu awọn iyokù ẹnikan kò jẹ daṣa ati dapọ mọ wọn: ṣugbọn enia nkọ́ okiki wọn.

14 Ọ̀pọ awọn onigbagbọ́ li a si nyàn kún Oluwa, ati ọkọnrin ati obirin.

15 Tobẽ ti nwọn ngbé awọn abirùn jade si igboro, ti nwọn ntẹ́ wọn si ori akete, ati ibĩrọgbọku, bi o tilẹ ṣe kìki ojiji Peteru ti nrekọja lọ ni ki o le ṣijibò diẹ ninu wọn.

16 Ọpọ enia si ti ilu igberiko wá si Jerusalemu, nwọn nmu awọn abirùn enia wá, ati awọn ti ara kan fun ẹmi aimọ́: a si ṣe dida ara olukuluku wọn.

17 ¶ Nigbana li olori alufa dide, ti on ti gbogbo awọn ti nwọn wà lọdọ rẹ̀, (ti iṣe iyapa ti awọn Sadusi) inu wọn kún fun irira,

18 Nwọn si nawọ́, nwọn mu awọn aposteli, nwọn si fi wọn sinu tubu.

19 Ṣugbọn angeli Oluwa ṣí ilẹkun tubu li oru, nigbati o si mu wọn jade, o wipe,

20 Ẹ lọ, ẹ duro, ki ẹ si ma sọ gbogbo ọ̀rọ ìye yi fun awọn enia ni tempili.

21 Nigbati nwọn si gbọ́ yi, nwọn wọ̀ tempili lọ ni kutukutu, nwọn si nkọ́ni. Ṣugbọn olori alufa de, ati awọn ti mbẹ lọdọ rẹ̀, nwọn si pè apejọ, ati gbogbo awọn igbimọ awọn ọmọ Israeli, nwọn si ranṣẹ si ile tubu lati mu wọn wá.

22 Ṣugbọn nigbati awọn onṣẹ de ibẹ̀, ti nwọn kò si ri wọn ni ile tubu, nwọn pada wá, nwọn si rò,

23 Wipe, Awa bá ile tubu o sé pinpin nitõtọ, ati awọn oluṣọ duro lode niwaju ilẹkun: ṣugbọn nigbati awa ṣí ilẹkun, awa kò bá ẹnikẹni ninu tubu.

24 Nigbati olori alufa, ati olori ẹṣọ́ tempili ati awọn olori alufa gbọ́ nkan wọnyi, o gọ́ wọn fun wọn pe, nibo li eyi o gbé jasi.

25 Nigbana li ẹnikan de, o wi fun wọn pe, Wò o, awọn ọkọnrin ti ẹnyin fi sinu tubu, nwọn duro ni tempili, nwọn si nkọ́ awọn enia.

26 Nigbana li olori ẹṣọ́ pẹlu awọn onṣẹ lọ, nwọn mu wọn wá li ailò agbara: nitoriti nwọn bẹ̀ru awọn enia, ki a má ba sọ wọn li okuta.

27 Nigbati nwọn si mu wọn de, nwọn mu wọn duro niwaju ajọ igbimọ: olori alufa si bi wọn lẽre,

28 Wipe, Awa kò ti kìlọ fun nyin gidigidi pe, ẹnyin kò gbọdọ fi orukọ yi kọ́ni mọ́? wo o, ẹnyin fi ẹkọ́ nyin kún Jerusalemu, ẹnyin si npete ati mu ẹ̀jẹ ọkọnrin yi wá si ori wa.

29 ¶ Ṣugbọn Peteru ati awọn aposteli iyokù dahùn, nwọn si wipe, Awa kò gbọdọ má gbọ́ ti Ọlọrun jù ti enia lọ.

30 Ọlọrun awọn baba wa li o gbé Jesu dide, ẹniti ẹnyin pa, ti ẹnyin si fi há lori igi.

31 On li Ọlọrun fi ọwọ́ ọtún rẹ̀ gbéga lati jẹ Ọmọ alade ati Olugbala, lati fi ironupiwada fun Israeli, ati idariji ẹ̀ṣẹ.

32 Awa si li ẹlẹri rẹ̀ si nkan wọnyi; ati Ẹmí Mimọ́ pẹlu, ti Ọlọrun fifun awọn ti o gbọ́ tirẹ̀.

33 ¶ Nigbati nwọn gbọ́ eyini, àiya wọn gbà ọgbẹ́ de inu, nwọn gbìro ati pa wọn.

34 Nigbana li ọkan ninu ajọ na, ti a npè ni Gamalieli, Farisi ati amofin, ti o niyìn gidigidi lọdọ gbogbo enia, o dide duro, o ni ki a mu awọn aposteli bì sẹhin diẹ;

35 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin ọkọnrin

Digitized by Google

Israeli, ẹ kiyesi ara nyin li ohun ti ẹnyin
npete ati ṣe si awọn ọkọnrin wọnyi.
36 Nitori ṣaju ọjọ wọnyi ni Teuda dide,
o nṣe fefé pe ẹnikan nla li on ; ẹniti ìwọn
irinwo ọkọnrin gbatì : ẹniti a pa ; ati ìwọn
gbogbo awọn ti o gbà tirẹ̀ gbọ́, a tú wọn
ká, a si sọ wọn di asan.
37 Lẹhin ọkọnrin yi ni Juda ti Galili
dide lakoko kikà enia, o si fà enia pipọ
lẹhin rẹ̀ : on pẹlu o gbé ; ati gbogbo iye
awọn ti o gbà tirẹ̀ gbọ́, a fọn wọn ká.
38 Njẹ emi wi fun nyin nisisiyi, Ẹ gafa-
ra fun awọn ọkọnrin wọnyi, ki ẹ si jọwọ
wọn jẹ : nitori bi o ba ṣepe ìmọ tabi iṣẹ yi
ba ṣe ti enia, yio di asan :
39 Ṣugbọn bi ti Ọlọrun ba ni, ẹnyin kì
yio le bì i ṣubu ; ki o ma ba jẹ pe, a ri
nyin ẹ mba Ọlọrun jà.
40 Nwọn si tẹ̀ si tirẹ̀ : nigbati nwọn si
pè awọn aposteli, ti nwọn lù wọn, nwọn
kìlọ fun wọn pe, ki nwọn ki o máṣe sọ̀rọ li
orukọ Jesu mọ́, nwọn si jọwọ wọn lọwọ lọ.
41 ¶ Nwọn si lọ kuro niwaju ajọ igbi-
mọ : nwọn nyọ̀ nitori ti a kà wọn yẹ si ìya
ijẹ nitori orukọ rẹ̀.
42 Ati li ojojumọ́ ni tempili ati lati ile
de ile, nwọn kò dẹkun ikọ́ni, ati lati wasu
Jesu Kristi.

## ORI 6.

ATI li ọjọ wọnni, nigbati iye awọn ọmọ-
ẹhin npọ̀ si i, ikùn sinu wà ninu awọn
Hellene si awọn Heberu, nitoriti a nṣe
igbagbé awọn opó wọn ni ipinfunni ojoju-
mọ́.
2 Nigbana li awọn mejila pè ọpọlọpọ
awọn ọmọ-ẹhin jọ̀, nwọn wipe, Kò yẹ ti
awa iba fi ọ̀rọ Ọlọrun silẹ, ki a si ma sìn
tabili.
3 Nitorina, ará, ẹ wò ọkọnrin meje ninu
nyin, olorukọ rere, ẹniti o kún fun Ẹmí
Mimọ́, ati fun ọgbọ́n, ẹniti awa iba yàn si
iṣẹ yi.
4 Ṣugbọn awa o fi ara wa fun adura
nigbagbogbo, ati fun iṣẹ iranṣẹ ọ̀rọ na.
5 ¶ Ọ̀rọ na si tọ́ loju gbogbo ijọ : nwọn
si yàn Stefanu, ọkọnrin ti o kún fun igba-
gbọ́ ati fun Ẹmí Mimọ́, ati Filippi ati
Prokoru, ati Nikanoru, ati Timoni, ati
Parmena, ati Nikola alawọṣe Ju ara Anti-
oku :
6 Ẹniti nwọn mu wá siwaju awọn apos-
teli : nigbati nwọn si gbadura, nwọn fi
ọwọ́ le wọn.
7 Ọ̀rọ Ọlọrun si gbilẹ ; iye awọn ọmọ-
ẹhin si pọ̀ si i gidigidi ni Jerusalemu ; ati
ọpọ ninu ẹgbẹ awọn alufa fetisi igbagbọ́.
8 Ati Stefanu, ti o kún fun igbagbọ́, ati
fun agbara, o ṣe iṣẹ iyanu, ati iṣẹ aṣẹ nla
lãrin awọn enia.
9 ¶ Nigbana li awọn kan dide ninu
sinagogu, ti a npè ni ti awọn Libertine,
ati ti ara Kirene, ati ti ara Aleksandria,
ati ninu awọn ara Kilikia, ati ti Asia,
nwọn mba Stefanu jiyàn.
10 Nwọn kò si le kò ọgbọ́n ati ẹmí ti o
fi nsọ loju.
11 Nigbana ni nwọn lọ lati bẹ̀ abẹtẹlẹ
awọn ọkọnrin, ti nwọn wipe, Awa gbọ́
ọkọnrin yi nsọ ọ̀rọ buburu si Mose ati si
Ọlọrun.
12 Nwọn si rú awọn enia soke, ati awọn
alàgba, ati awọn akọwe, nwọn dide si i,
nwọn gbá a mu, nwọn mu u wá si ajọ.
13 Nwọn si mu awọn ẹlẹri eke wá, ti
nwọn wipe, Ọkọnrin yi kò simi lati sọ ọ̀rọ
buburu si ibi mimọ́ yi, ati si ofin :
14 Nitori awa gbọ́ o wipe, Jesu ti Nasa-
reti yi, yio fọ́ ibi yi, yio si pa iṣe tí Mose
fifun wa dà.
15 Ati gbogbo awọn ti o si joko ni ajọ,
tẹjumọ́ ọ iwò, nwọn nwò oju rẹ̀ bi ẹnipe
oju angeli.

## ORI 7.

NIGBANA li olori alufa dahùn wipe,
Nkan wọnyi ha ri bẽ bi ?
2 O si dahùn wipe, Alàgba, ará, ati
baba, ẹ fetisi i ; Ọlọrun ogo fi ara hàn fun
Abrahamu baba wa, nigbati o wà ni Meso-
potamia, ki o to ṣe atipo ni Karani,
3 O si wi fun u pe, Lọ kuro ni ilẹ rẹ,
ati lọdọ awọn ibatan rẹ, ki o si wá si ilẹ ti
emi o fi hàn ọ.
4 Nigbana li o si lọ kuro ni ilẹ awọn ara
Kaldea, o si ṣe atipo ni Karani : lẹhin
igbati baba rẹ̀ kú, lati ibẹ̀ li o ti ṣí i wá si
ilẹ yi, nibiti ẹnyin ngbé nisisiyi.
5 Kò si fun u to bi atẹlẹsẹ ilẹ ninu rẹ̀ :
ṣugbọn o leri pe, on o fi i fun u ni ilẹ-nini,
ati fun awọn irú-ọmọ rẹ̀ lẹhin rẹ̀, nigbati
kò ti ili ọmọ.
6 Ọlọrun si sọ bayi pe, Irú ọmọ rẹ̀ yio
ṣe atipo ni ilẹ miran ; nwọn o si sọ wọn di
ondè, nwọn o si pọ́n wọn loju ni irinwo
ọdún.
7 Ọlọrun wipe, Orilẹ-ède na ti nwọn o
wà li ondè fun, li emi o da lẹjọ : lẹhin
eyini ni nwọn o jade kuro, nwọn o wá sìn
mi nihinyi.
8 O si ba a da majẹmu ikọlà : bẹ̃li

Digitized by Google

Abrahamu bí Isaaki, o kọ ọ ni ilà ni ijọ
kẹjọ; Isaaki si bí Jakọbu; Jakọbu si bi
awọn baba nla mejila.
9 Awọn baba nla si ṣe ilara Josefu,
nwọn si tà a si Egipti: ṣugbọn Ọlọrun wà
pẹlu rẹ̀.
10 O si yọ ọ kuro ninu ipọnju rẹ̀ gbo-
gbo, o si fun u li oju rere ati ọgbọ́n li oju
Farao ọba Egipti; on si fi i jẹ bãlẹ Egipti
ati gbogbo ile rẹ̀.
11 O si ṣe, ìyan kan wá imu ni gbogbo
ilẹ Egipti ati ni Kenaani, ati ipọnju pipọ:
awọn baba wa kò si ri onjẹ.
12 Ṣugbọn nigbati Jakọbu gbọ́ pe alika-
ma mbẹ ni Egipti, o rán awọn baba wa lọ
lẹrinkini.
13 Nigba arinkeji Josefu fi ara rẹ̀ hàn
fun awọn arakọnrin rẹ̀; a si fi awọn ará
Josefu hàn fun Farao.
14 Nigbana ni Josefu ranṣẹ, o si pè
Jakọbu baba rẹ̀ si ọdọ, ati gbogbo awọn
ibatan rẹ̀, arundilọgọrin ọkàn.
15 Bẽni Jakọbu sọkalẹ lọ si Egipti, o si
kú, on ati awọn baba wa,
16 A si rù wọn lọ si Sikemu, a si tẹ́ wọn
sinu iboji ti Abrahamu rà ni iye fadaka
lọwọ awọn ọmọ Emoru baba Sikemu.
17 Ṣugbọn bi akokò majẹmu ti Oluwa
da fun Abrahamu ti kù si dẹdẹ, awọn enia
na nrú, nwọn si nrẹ̀ ni Egipti,
18 Titi ọba miran fi jẹ, ti kò mọ̀ Josefu.
19 On na li o ṣe arekereke si awọn iba-
tan wa, nwọn si hùwa buburu si awọn
baba wa, tobẽ ti nwọn fi já awọn ọmọ-ọwọ
wọn lọwọ wọn, nitori ki nwọn ki o máṣe
yè.
20 Li akokò igba ti a bí Mose, ẹniti o li
ẹwà loju Ọlọrun, ti nwọn si bọ́ li oṣù mẹta
ni ile baba rẹ̀:
21 Nigbati nwọn si já a sọnù, ọmọbirin
Farao he e, o si tọ́ ọ dàgba li ọmọ ara rẹ̀.
22 A si kọ́ Mose ni gbogbo ọgbọ́n ará
Egipti, o si pọ̀ li ọ̀rọ ati ni iṣe.
23 Nigbati o si di ẹni ogoji ọdún, ọkàn
rẹ̀ fà si ati lọ ibẹ̀ awọn ọmọ Israeli ará
rẹ̀ wò.
24 Nigbati o ri ọkan ninu wọn ti njìya,
o gbijà rẹ̀, o gbẹsan ẹniti nwọn njẹ ni ìya,
o si pa ara Egipti na:
25 O si ṣebi awọn ará on o mọ̀ bi Ọlọrun
yio ti ti ọwọ́ on gbà wọn: ṣugbọn nwọn kò
mọ̀.
26 O si di ijọ keji o fi ara rẹ̀ hàn fun
wọn bi nwọn ti njà, on iba si là wọn, o
wipe, Alàgba, ará li ẹnyin; ẽṣe ti ẹnyin fi
nṣe ohun ti kò tọ́ si ara nyin?
27 Ṣugbọn ẹniti o finran si ẹnikeji rẹ̀, o
tì i kuro, o wipe, Tali o fi ọ jẹ olori tabi
onidajọ wa?
28 Iwọ nfẹ pa mi bi iwọ ti pa ará Egipti
laná?
29 Nigbana ni Mose sá nitori ọ̀rọ yi, o
si wa idi alejò ni ilẹ Madiani, nibiti o gbé
bí ọmọ meji.
30 Nigbati ogoji ọdún si pé, angeli Olu-
wa fi ara rẹ̀ hàn a li òke Sinai ni ijù, ninu
ọwọ́ iná ni igbẹ́.
31 Nigbati Mose si ri i, ẹnu yà a si iran
na: nigbati o si sunmọ ọ lati wò o fín,
ohùn Oluwa ti inu iná kọ si i,
32 Wipe, Emi li Ọlọrun awọn baba rẹ,
Ọlọrun Abrahamu, ati Ọlọrun Isaaki, ati
Ọlọrun Jakọbu. Nigbana ni Mose warìri,
kò si daṣa ati wò o mọ́.
33 Oluwa si wi fun u pe, Tú bata rẹ
kuro li ẹsẹ rẹ: nitori ibi ti o gbé duro ni
ilẹ mimọ́ ni.
34 Ni riri mo ti ri ipọnju awọn enia mi
ti mbẹ ni Egipti, mo si ti gbọ́ gbigbin wọn,
mo si sọkalẹ wá lati da wọn ni ide. Iwọ
wá nisisiyi, emi o rán ọ lọ si Egipti.
35 Mose na yi ti nwọn kọ̀, wipe, Tali o
fi ọ jẹ olori tabi onidajọ? on na li Ọlọrun
rán lọ lati ṣe olori ati oludande lati ọwọ́
angeli na lọ, ti o fi ara hàn a ni igbẹ́.
36 On li o mu wọn jade, lẹhin igbati o
fi iṣẹ iyanu, ati iṣẹ àmi hàn ni ilẹ Egipti,
ati li Okun pupa, ati li aginjù li ogoji
ọdún.
37 ¶ Eyi ni Mose na ti o wi fun awọn
ọmọ Israeli pe, Woli kan li Oluwa Ọlọrun
nyin yio gbé dide fun nyin ninu awọn
arakọnrin nyin, bi emi; on ni ki ẹnyin ki
o gbagbọ́.
38 Eyi na li ẹniti o wà ninu ijọ ni ijù
pẹlu angeli na ti o mba a sọ̀rọ li òke Sinai,
ati pẹlu awọn baba wa: ẹniti o gbà ọ̀rọ ìye
lati fifun wa:
39 Ẹniti awọn baba wa kò fẹ gbagbọ́,
ṣugbọn nwọn tì i kuro lọdọ wọn, nwọn si
yipada li ọkàn wọn si Egipti,
40 Nwọn wi fun Aaroni pe, Da oriṣa
fun wa ti yio ma tọna ṣaju wa: nitori bi o
ṣe ti Mose yi ti o mu wa ti ilẹ Egipti wá,
awa kò mọ̀ ohun ti o ṣe e.
41 Nwọn si yá ere ẹgbọ̀rọ malu ni ijọ
wọnni, nwọn si rubọ fun ere na, nwọn si
nyọ̀ si iṣẹ ọwọ́ ara wọn.
42 Nigbana li Ọlọrun si pada, o fi wọn
silẹ lati ma sìn irawọ oju ọrun; bi a ti kọ
ọ ninu iwe awọn woli pe, Ẹnyin ara ile
Israeli, ẹnyin ha pa ẹran rubọ, tabi ẹnyin



Digitized by Google

ha mu ẹbọ fun mi wá li aginjù ni ìwọn ogoji ọdún bi?
43 Pẹlu-pẹlu ẹnyin tẹwọgbà agọ́ Moloku, ati irawọ Remfani ọlọrun nyin, aworan ti ẹnyin ṣe lati ma bọ wọn: emi o si kó nyin lọ rekọja Babiloni.
44 Agọ́ ẹri wà lọdọ awọn baba wa ni ijù, bi o ti pinnu rẹ̀, o nsọ fun Mose pe, ki o ba le ṣe e gẹgẹ bi apẹrẹ ti o ti ri.
45 Ti awọn atẹle baba wa si mu ba Joṣua wá si ilẹ awọn Keferi, ti Ọlọrun lé jade kuro niwaju awọn baba wa, titi o fi di igba ọjọ Dafidi;
46 Ẹniti o ri ore niwaju Ọlọrun, ti o si nfẹ pagọ́ fun Ọlọrun Jakọbu.
47 Ṣugbọn Solomoni li o kọ́ ile fun u.
48 Ṣugbọn Ọgá-ogo kì igbé ile ti a fi ọwọ kọ́; gẹgẹ bi woli ti wi pe,
49 Ọrun ni itẹ́ mi, aiye si li apoti itisẹ mi: irú ile kili ẹnyin o kọ́ fun mi? li Oluwa wi; tabi ibo ni ibi isimi mi?
50 Ọwọ́ mi kò ha ṣe gbogbo nkan wọnyi?
51 ¶ Ẹnyin ọlọrùn-lile ati alaikọla àiya on etí, nigbagbogbo li ẹnyin ima dèna Ẹmí Mimọ́; gẹgẹ bi baba nyin, bẹ̃li ẹnyin.
52 Tani ninu awọn wọli ti awọn baba nyin kò ṣe inunibini si? nwọn si ti pa awọn ti o ti nsọ ti wíwa Ẹni Olõtọ na tẹlẹ; ẹniti ẹnyin si ti di amọ̀na si ati olupa:
53 Ẹniti o fi iwasu awọn angeli gbà ofin, ti nwọn kò si pa a mọ́.
54 ¶ Nigbati nwọn gbọ́ nkan wọnyi, àiya wọn gbà ọgbẹ̀ de inu, nwọn si pahin si i keke.
55 Ṣugbọn on kún fun Ẹmí Mimọ́, o tẹjumọ́, o nwò ọrun, o si ri ogo Ọlọrun, ati Jesu nduro li ọwọ́ ọtún Ọlọrun.
56 O si wipe, Wò o, mo ri ọrun ṣí silẹ, ati Ọmọ-enia nduro li ọwọ́ ọtún Ọlọrun.
57 Nigbana ni nwọn kigbe li ohùn rara, nwọn si dì eti wọn, nwọn fi ọkàn kan ró lù u,
58 Nwọn si wọ́ ọ sẹhin ode ilu na, nwọn sọ ọ li okuta: awọn ẹlẹri si fi aṣọ wọn lelẹ li ẹsẹ ọmọkọnrin kan ti a npè ni Saulu.
59 Nwọn sọ Stefanu li okuta, o npè Ọlọrun, o si nwipe, Jesu Oluwa, gbà ẹmí mi.
60 O si kunlẹ, o kigbe li ohùn rara pe, Oluwa, má kà ẹ̀ṣẹ yi si wọn li ọrùn. Nigbati o si wi eyi, o sùn.

## ORI 8.

SAULU si li ohùn si ikú rẹ̀. Nigbana inunibini nla kan wà fun ijọ ti o wà ni Jerusalemu; a si tú gbogbo wọn kalẹ já àgbegbe Judea on Samaria, bikoṣe kìki awọn aposteli.
2 Awọn enia rere si dì okú Stéfanu, nwọn si pohùnrere ẹkún sori rẹ̀.
3 Ṣugbọn bi o ṣe ti Saulu ni, o nfọ́ ijọ enia Ọlọrun tútu, o nwọ̀ ojojule, o si nmu awọn ọkọnrin ati obirin, o nfi wọn sinu tubu.
4 Awọn ti nwọn si túka nlọ si ibi gbogbo, nwọn nwasu ọ̀rọ na.
5 Filippi si sọkalẹ lọ si ilu Samaria, o nwasu Kristi fun wọn.
6 Awọn enia si fi ọkàn kan fi iye si ohun ti Filippi nsọ, nwọn ngbọ́, nwọn si nri iṣẹ aṣẹ ti o nṣe.
7 Nitori awọn ẹmi aimọ́ nkigbe li ohùn rara, nwọn jade kuro lara awọn pipọ ti nwọn gùn: ati pipọ awọn ti ẹ̀gba mu, ati awọn amokun, a si ṣe dida ara wọn.
8 Ayọ̀ pipọ si wà ni ilu na.
9 Ṣugbọn ọkọnrin kan wà ni ilu na, ti a npè ni Simoni, ti ima ṣe oṣó si awọn ara Samaria ri, ama wipe enia nla kan li on:
10 Ẹniti gbogbo wọn fiyesi, ati ewe ati àgba, nwipe, Ọkọnrin yi ni agbara nla Ọlọrun.
11 On ni nwọn si bọ̀wọ fun, nitori igba atijọ li o ti nṣe oṣó si wọn.
12 Ṣugbọn nigbati nwọn gbà Filippi gbọ́ ti nwasu ohun ijọba Ọlọrun, ati orukọ Jesu Kristi, a baptisi wọn, ati ọkọnrin ati obirin.
13 Simoni tikararẹ̀ si gbagbọ́ pẹlu: nigbati a si baptisi rẹ̀, o si mba Filippi joko, o nwò iṣẹ àmi ati iṣẹ aṣẹ ti nti ọwọ́ Filippi ṣe, ẹnu si yà a.
14 Nigbati awọn aposteli ti o wà ni Jerusalemu gbọ́ pe awọn ara Samaria gbà ọ̀rọ Ọlọrun, nwọn rán Peteru on Johannu si wọn:
15 Awọn ẹniti o si gbadura fun wọn, nigbati nwọn sọkalẹ, ki nwọn ki o le ri Ẹmí Mimọ́ gbà:
16 Nitori titi o fi di igbana kò ti ibà le ẹnikẹni ninu wọn; kìki a baptisi wọn li orukọ Jesu Oluwa ni.
17 Nigbana ni nwọn fi ọwọ́ le wọn, nwọn si gbà Ẹmí Mimọ́.
18 Nigbati Simoni ri pe nipa ifi ọwọ́ leni li a nti ọwọ́ awọn aposteli fi Ẹmí Mimọ́ fun ni, o ṣe ileri owo fun wọn.
19 O wipe, Ẹ fun mi ni irú aṣẹ yi pẹlu, ki ẹnikẹni ti mo ba fi ọwọ́ le, ki o le ri Ẹmí Mimọ́ gbà.
20 Ṣugbọn Peteru da a lohùn wipe, Owo

Digitized by Google

rẹ a ṣegbé pẹlu rẹ, nitoriti iwọ ṣebi ama fi owo rà ẹ̀bun Ọlọrun.

21 Iwọ kò ni ipa, tabi ipín ni ọ̀ràn yi: nitori ọkàn rẹ kò ṣe dẽdẽ niwaju Ọlọrun.

22 Nitorina ronupiwada ìwa buburu rẹ yi, ki o si gbadura sọdọ Ọlọrun, bọya yio dari ete ọkàn rẹ jì ọ.

23 Nitoriti mo woye pe, iwọ wà ninu ikorò orõro, ati ni ìde ẹ̀ṣẹ.

24 Nigbana ni Simoni dahùn, o si wipe, Ẹ gbadura sọdọ Oluwa fun mi, ki ọkan ninu ohun ti ẹnyin sọ wọnyi ki o máṣe ba mi.

25 Ati awọn nigbati nwọn si ti jẹri, ti nwọn si ti wasu ọ̀rọ Oluwa, nwọn pada lọ si Jerusalemu, nwọn si wasu ihin-rere ni iletò pipọ ti awọn ara Samaria.

26 Angeli Oluwa si sọ fun Filippi, pe, Dide ki o si ma lọ si ìha gusu li ọ̀na ti o ti Jerusalemu lọ si Gasa, ti iṣe ijù.

27 Nigbati o si dide, o lọ; si kiyesi i, ọkọnrin kan ara Etiopia, iwẹfa ọlọlá pipọ lọdọ Kandake ayaba awọn ara Etiopia, ẹniti iṣe olori gbogbo iṣura rẹ̀, o si wá lati gbadura ni Jerusalemu.

28 Bi o ti npada lọ, ti o si joko ninu kẹkẹ́ rẹ̀, o nkà iwe woli Isaiah.

29 Nigbana li Ẹmí wi fun Filippi pe, Lọ, ki o si da ara rẹ pọ̀ mọ́ kẹkẹ́ yi.

30 Filippi si sure lọ, o gbọ́, o nkà iwe woli Isaiah, o si bi i pe, Iwe ti iwọ nkà nì, o yé ọ?

31 O si dahùn wipe, Yio ti ṣe yé mi, bikoṣepe ẹnikan fi itumọ̀ rẹ̀ hàn mi? O si bẹ̀ Filippi ki o gòke wá, ki o si ba on joko.

32 Ibi iwe-mimọ́ ti o nkà na li eyi, A fà a bi agutan lọ si pipa; ati bi ọdọ-agutan iti idakẹ niwaju olurẹrun rẹ̀, bẽni kò yà ẹnu rẹ̀:

33 Ni irẹlẹ rẹ̀ a gbà idajọ rẹ̀: tali o si le pìtan iran rẹ̀? nitori a gbà ẹmí rẹ̀ kuro li aiye.

34 Iwẹfa si da Filippi lohùn, o ni, Mo bẹ̀ ọ, tani woli na sọ eyi si? si ara rẹ̀, tabi si ẹlomiran?

35 Nigbana ni Filippi si yà ẹnu rẹ̀, o si bẹ̀rẹ si i ni ibi iwe-mimọ́ na, o si wasu Jesu fun u.

36 Bi nwọn si ti nlọ li ọ̀na, nwọn de ibi omi kan: iwẹfa si wipe, Wò o, omi niyi; kili o dá mi duro lati baptisi?

37 Filippi si wipe, Bi iwọ ba gbagbọ́ tọkàntọkan, a le baptisi rẹ. O si dahùn o ni, Mo gbagbọ́ pe Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun ni.

38 O si wipe ki a dá kẹkẹ́ duro: awọn mejeji si sọkalẹ lọ sinu omi, ati Filippi ati iwẹfa; o si baptisi rẹ̀.

39 Nigbati nwọn si jade kuro ninu omi, Ẹmí Oluwa ta Filippi pá, iwẹfa kò si ri i mọ́: on si mu ọ̀na rẹ̀ pọ̀n, o nlọ, o nyọ̀.

40 Ni Asotu li a si wa iri Filippi; bi o ti nrekọja lọ, o nwasu ni gbogbo ilu, titi o fi de Kesarea.

## ORI 9.

SUGBỌN Saulu, o nmí ìlọ ati pipa sibẹ si awọn ọmọ-ẹhin Oluwa, o tọ̀ olori alufa lọ.

2 O bẹ̀bẹ iwe lọwọ rẹ̀ si Damasku si sinagogu pe, bi on ba ri ẹnikẹni li ọ̀na yi, iba ṣe ọkọnrin, iba ṣe obirin, ki on le mu wọn ni didè wá si Jerusalemu.

3 Bi o si ti nlọ, o si sunmọ eti Damasku: imọlẹ si mọ́ yi i ká lojijì lati ọrun wá:

4 O si ṣubu lulẹ, o gbọ́ ohùn ti o nfọ̀ si i pe, Saulu, Saulu, ẽṣe ti iwọ fi nṣe inunibini si mi?

5 On si wipe, Iwọ tani, Oluwa? Oluwa si dahùn pe, Emi Jesu ni, ẹniti iwọ nṣe inunibini si: o ṣoro fun ọ lati tapá si ẹgún.

6 O si nwarìri, ẹnu si yà a, o ni Oluwa kini iwọ nfẹ ki emi ki o ṣe? Oluwa si wi fun u pe, Dide, ki o si lọ si ilu na, nibẹ̀ li a o sọ fun ọ li ohun ti iwọ o ṣe.

7 Awọn ọkọnrin ti si mba a rìn pọ̀ duro, kẹkẹ pa mọ́ wọn li ẹnu, nwọn ngbọ́ ohùn, ṣugbọn nwọn kò ri ẹnikan.

8 Saulu si dide ni ilẹ; nigbati oju rẹ̀ si ṣí, kò ri ẹnikẹni: ṣugbọn nwọn fà a li ọwọ́, nwọn si mu u wá si Damasku.

9 O si gbé ijọ mẹta li airina, kò si jẹ, bẽni kò si mu.

10 ¶ Ọkọnrin kan ọmọ-ẹhin si wà ni Damasku, ti a npè ni Anania, on li Oluwa si wi fun li ojuran pe, Anania. O si dahùn wipe, Wò o, emi niyi, Oluwa.

11 Oluwa si wi fun u pe, Dide, ki o si lọ si ọ̀na igboro ti a npè ni Ọganran, ki iwọ ki o si bère ẹnikan, ti a npè ni Saulu, ara Tarsu, ni ile Juda: sá wo o, o ngbadura.

12 On si ti ri ọkọnrin kan li ojuran ti a npè ni Anania o wọle, o si fi ọwọ́ le e, ki o le riran rẹ̀.

13 Anania si dahùn wipe, Oluwa, mo ti gburó ọkọnrin yi lọdọ ọ̀pọ enia, ìwọn buburu ti o ṣe si awọn enia mimọ́ rẹ ni Jerusalemu.

14 O si gbà agbara lati ọdọ awọn olori

Digitized by Google

alufa wá si ihinyi, lati dè gbogbo awọn ti
npè orukọ rẹ.
15 Ṣugbọn Oluwa wi fun u pe, Mã ba
tirẹ lọ: nitoriti iṣe ohun-ìlo àyo fun mi,
lati mu orukọ mi lọ si iwaju awọn Keferi,
ati awọn ọba, ati niwaju awọn ọmọ Israeli:
16 Nitori emi o fi hàn a ni iya ohun
pipọ ti yio jẹ nitori orukọ mi.
17 Anania si mu ọ̀na rẹ̀ pọ̀n, o si wọ̀ ile
na; nigbati o si fi ọwọ́ rẹ̀ le e, o ni, Saulu
Arakọnrin, Oluwa li o rán mi, Jesu ti o fi
ara hàn fun ọ li ọ̀na bi iwọ ti mbọ̀ wá, ki
iwọ ki o le riran rẹ, ki o si le kún fun Ẹmí
Mimọ́.
18 Lojukanna ohun kan bọ́ kuro li oju
rẹ̀ bi ipẹpẹ́: o si riran; o si dide, a baptisi
rẹ̀.
19 Nigbati o si jẹun, ara rẹ̀ le. Saulu
si wà pẹlu awọn ọmọ-ẹhin ni Damasku ni
ijọ melokan.
20 Lojukanna o si wasu Kristi ninu
sinagogu pe, on li Ọmọ Ọlọrun.
21 Ṣugbọn ẹnu yà gbogbo awọn ti o
ngbọ́, nwọn si wipe, Ọkọnrin yi kọ nṣe
inunibini si awọn ti npè orukọ yi ni Jeru-
salemu, ti o si ti itori na wá si ihinyi, ki o
le mu wọn ni didè lọ ifi fun awọn olori
alufa?
22 Ṣugbọn agbara Saulu npọ̀ si i, o si
dãmu awọn Ju ti o wà ni Damasku, o nfi
hàn pe, eyiyi na ni Kristi.
23 ¶ Lẹhin igbati ọjọ pipọ kọja, awọn
Ju ngbìro lati pa a:
24 Ṣugbọn ìdena wọn di mimọ̀ fun Saulu.
Nwọn si nṣọ ẹnu-ọ̀na li ọsán ati li oru lati
pa a.
25 Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin mu u li
oru, nwọn si sọ̀ ọ kalẹ lara odi ninu agbọ̀n.
26 Nigbati Saulu si de Jerusalemu, o
pete ati ba awọn ọmọ-ẹhin dàpọ: ṣugbọn
gbogbo wọn bẹ̀ru rẹ̀, nwọn kò si gbagbọ́ pe
o di ọmọ-ẹhin kan.
27 Ṣugbọn Barnaba mu u, o si sìn i wá
sọdọ awọn aposteli, o si sọ idi rẹ̀ fun wọn
bi o ti ri Oluwa li ọ̀na, ati bi o si ti ba a
sọ̀rọ, ati bi o si ti fi igboiya wasu ni
Damasku li orukọ Jesu.
28 O si wà pẹlu wọn, o nwọle o si njade
ni Jerusalemu.
29 O si fi igboiya sọ̀rọ li orukọ Jesu
Oluwa, o si njà awọn ara Hellene ni iyàn:
ṣugbọn nwọn npete ati pa a.
30 Nigbati awọn arakọnrin mọ̀, nwọn
mu u sọkalẹ lọ si Kesarea, nwọn si rán a lọ
si Tarsu.
31 Nigbana ni ijọ enia wà li alafia yi
gbogbo Judea ká ati ni Galili ati ni Sa-
maria, nwọn nfi ẹsẹ mulẹ; nwọn si nrìn ni
ìbẹru Oluwa, nwọn si npọ̀ si i ni itunu
Ẹmí Mimọ́.
32 ¶ O si ṣe, nigbati Peteru nkọja là
ẹkùn gbogbo lọ, o sọkalẹ tọ̀ awọn enia
mimọ́ ti o wà ni Lidda lọ pẹlu.
33 Nibẹ̀ li o gbé bá ọkọnrin kan ti a
npè ni Enea, ti o ti dubulẹ lori akete li
ọdún mẹjọ, o nrùn ẹ̀gba.
34 Peteru si wi fun u pe, Enea, Jesu
Kristi mu ọ lara da: dide, ki o si tún
akete rẹ ṣe. O si dide lojukanna.
35 Gbogbo awọn ti o si wà ni Lidda ati
Saroni ri i, nwọn si yipada si Oluwa.
36 ¶ Ọmọ-ẹhin kan si wà ni Joppa ti a
npè ni Tabita, ni itumọ̀ rẹ̀ ti a npè ni
Dorka: obirin yi pọ̀ ni iṣẹ ore, ati ni iṣẹ
ọrẹ-ãnu ti o ṣe.
37 O si ṣe ni ijọ wọnni, ti o ṣaisàn, o si
kú: nigbati nwọn wẹ̀ ẹ tan, nwọn tẹ́ ẹ si
gbàngan kan loke.
38 Bi Lidda si ti sunmọ Joppa, nigbati
awọn ọmọ-ẹhin ti gbọ́ pe Peteru wà nibẹ̀,
nwọn rán ọkọnrin meji si i lọ ibẹ̀ ẹ pe, ki
o máṣe roju ati tọ̀ wọn wá nisisiyi.
39 Nigbana ni Peteru dide, o si bá wọn
wá. Nigbati o de, nwọn mu u wá si gbàn-
gan oke na: ati gbogbo awọn opó duro ti
i, nwọn nsọkun, nwọn si nfi ẹ̀wu ati aṣọ ti
Dorka dá hàn a, nigbati o wà lãye.
40 Nigbati Peteru si rán gbogbo wọn
sọde, ti o kunlẹ, o gbadura; o si yipada si
okú, o ni, Tabita, dide. O si ṣí oju rẹ̀:
nigbati o si wò Peteru, o dide joko.
41 O si nà ọwọ́ rẹ̀ si i, o fà a dide, ni-
gbati o si pè awọn enia mimọ́ ati awọn
opó, o mu u wá lãye.
42 A si gbọ́ ọ yi gbogbo Joppa ká;
awọn enia pipọ si gba Oluwa gbọ́.
43 O si ṣe, o gbé ọjọ pipọ ni Joppa lọdọ
ọkọnrin kan Simoni alawọ.

## ORI 10.

ỌKỌNRIN kan si wà ni Kesarea ti a
npè ni Korneliu, balogun ọrún ti
ẹgbẹ́-ogun ti a npè ni ẹgbẹ ti Itali,
2 Olufọkansìn enia, ati ẹniti o bẹ̀ru Ọlọ-
run tiletile rẹ̀ gbogbo, ẹniti o nta ọrẹ-ãnu
pipọ fun awọn enia, a si ma gbadura sọdọ
Ọlọrun nigbagbogbo.
3 O riran gbangba niwọn wakati kẹsan
ọjọ, angeli Ọlọrun kan wọle tọ̀ ọ wá, o si
wi fun u pe, Korneliu.
4 Nigbati o si tẹjumọ́ ọ, ẹ̀ru ba a, o ni,
Kini, Oluwa? O si da a lohùn pe, Adura

Digitized by Google

rẹ ati ọrẹ-ãnu rẹ goke fun iranti niwaju
Ọlọrun.
5 Si rán enia nisisiyi lọ si Joppa, ki
nwọn si pè Simoni wá, ẹniti apele rẹ̀ jẹ
Peteru:
6 O wọ̀ si ile ẹnikan Simoni alawọ, ti ile
rẹ̀ wà lẹba okun: on ni yio sọ fun ọ bi iwọ
o ti ṣe.
7 Nigbati angeli na ti o ba Korneliu
sọ̀rọ si ti fi i silẹ lọ, o nahùn,o si pè awọn
iranṣẹ ile rẹ̀ meji, ati ọmọ-ogun olufọkànsin
kan, ninu awọn ti ima duro tì i nigba-
gbogbo;
8 Nigbati o si ti sọ ohun gbogbo fun
wọn, o rán wọn lọ si Joppa.
9 ¶ Ni ijọ keji bi nwọn ti nlọ li ọ̀na
àjo wọn, ti nwọn kù ilu na si dẹ̀dẹ̀, Peteru
gòke àja lọ igbadura li akokò wakati kẹfa
ọjọ:
10 Ebi si bẹ̀rẹ si ipa gidigidi, on iba si
jẹun: ṣugbọn nigbati nwọn npèse, o bọ si
ojuran,
11 O si ri ọrun o ṣí, ohun-èlo kan si
sọkalẹ bi gọgọwu nla ti a dì leti igun mẹ-
rẹrin, ti a si nà silẹ:
12 Ninu rẹ̀ li oloriori ẹran ẹlẹsẹ mẹrin
aiye yi wà, ati ẹranko igbẹ́, ati ohun ti
nrakò, ati ẹiyẹ oju ọrun.
13 Ohùn kan si fọ̀ si i pe, Dide, Peteru;
mã pa ki o si mã jẹ.
14 Ṣugbọ̀n Peteru dahùn pe, Bẹ̃kọ,
Oluwa; nitori emi kò jẹ ohun èwọ ati
alaimọ̀ ri lai.
15 Ohùn na si tún fọ̀ si i nigba keji pe,
Ohun ti Ọlọrun ba ti wẹ̀nu, iwọ máṣe pè li
èwọ mọ́.
16 Eyiyi ṣe bẹ̃ li ẹrinmẹta: a si gbé
ohun-èlo na pada lọ soke ọrun.
17 Bi o ti ngọ́ Peteru ninu ara rẹ̀ bi a ba
ti mọ̀ iran ti on ri yi si, si wo o, awọn
ọkọnrin ti a rán ti ọdọ Korneliu wá de,
nwọn mbère ile Simoni, nwọn duro li ẹnu-
ọ̀na,
18 Nwọn nahùn bère bi Simoni ti a npè
ni Peteru, wọ̀ nibẹ̀.
19 ¶ Bi Peteru ti nronu iran na, Ẹmí si
wi fun u pe, Kiyesi i, awọn ọkọnrin mẹta
nwá ọ.
20 Njẹ dide, sọkalẹ ki o si ba wọn lọ,
má kọnnu ohunkohun: nitori emi li o rán
wọn.
21 Nigbana ni Peteru sọkalẹ tọ̀ awọn
ọkọnrin ti a rán si i lati ọdọ Korneliu wá;
o ni, Wò o, emi li ẹniti ẹnyin nwá: ere
idi rẹ̀ ti ẹnyin fi wá?
22 Nwọn si wipe, Korneliu balogun
ọrún, ọkọnrin olõtọ, ati ẹniti o bẹ̀ru Ọlọ-
run, ti o si ni ihin rere lọdọ gbogbo awọn
Ju, on li a ti ọdọ Ọlọrun wá ikọ́ nipasẹ
angeli mimọ́, ki o ranṣẹ si ọ, ki iwọ wá si
ile rẹ̀ lati gbọ́ ọ̀rọ li ẹnu rẹ.
23 Nigbana li o pè wọn wọle, o si mu
wọn wọ̀. O si di ijọ keji Peteru ba wọn lọ,
ati awọn kan ninu awọn arakọnrin ni Joppa
ba a lọ.
24 O si di ijọ kẹta nwọn wọ̀ Kesarea.
Korneliu si ti nreti wọn, o si ti pè awọn
ibatan ati awọn ọrẹ́ ti o wà nitosi jọ.
25 Bi Peteru si ti nwọle, Korneliu pade
rẹ̀, o wolẹ li ẹsẹ rẹ̀, o si foribalẹ fun u.
26 Ṣugbọn Peteru gbé e dide, o ni,
Dide; enia li emi tikara mi.
27 Bi o si ti mba a sọ̀rọ, o wọle, o si bá
awọn enia pipọ ti nwọn pejọ.
28 O si wi fun wọn pe, Ẹnyin mọ̀ bi kò
ti yẹ fun ẹniti iṣe Ju, lati ba ẹniti iṣe ara
ilẹ miran kẹgbẹ, on ati tọ̀ ọ wá; ṣugbọn
Ọlọrun ti fihàn mi pe, ki emi ki o máṣe pè
ẹnikẹni li èwọ tabi alaimọ́.
29 Nitorina ni mo si ṣe wá li aijiyàn, bi
a ti ranṣẹ si mi: njẹ mo bère, nitori kili
ẹnyin ṣe ranṣẹ si mi?
30 Korneliu si dahùn wipe, Lati ijọ
kẹrin ti emi ti ngbàwẹ niyi, titi o fi di
wakati yi; ni wakati kẹsan ọjọ emi si
ngbadura ni ile mi, si kiyesi i, ọkọnrin
kan alaṣọ àla, duro niwaju mi.
31 O si wipe, Korneliu, a gbọ́ adura
rẹ, a si gbà ọrẹ-ãnu rẹ ni iranti niwaju
Ọlọrun.
32 Njẹ ranṣẹ lọ si Joppa, ki o si pè
Simoni wá, ẹniti apele rẹ̀ jẹ Peteru; o wọ̀
ni ile Simoni alawọ lẹba okun: nigbati o
ba de, ẹniti yio sọ̀rọ fun ọ.
33 Lojukanna ni mo si ti ranṣẹ si ọ;
iwọ si ṣe rere ti iwọ fi wá. Gbogbo wa si
pé niwaju Ọlọrun nisisiyi, lati gbọ́ ohun
gbogbo ti a rán ọ lati ọdọ Ọlọrun wá.
34 ¶ Nigbana ni Peteru yà ẹnu rẹ̀, o ni,
Nitõtọ mo woye pe, Ọlọrun kì iṣe ojusaju
enia:
35 Ṣugbọn ninu gbogbo orilẹ-ède, ẹniti o
ba bẹ̀ru rẹ̀, ti o si ṣe otitọ, gbigbà ni lọdọ
rẹ̀.
36 Ọ̀rọ ti Ọlọrun rán si awọn ọmọ Israeli,
ti nwasu alafia nipa Jesu Kristi: (on li
Oluwa ohun gbogbo:)
37 Ọ̀rọ na ẹnyin mọ̀, ti a ti wasu yiká
gbogbo Judea, ti a bẹ̀rẹ si lati Galili wá,
lẹhin baptismu ti Johannu wasu;
38 Bi Ọlọrun ti dà Ẹmí Mimọ́ ati ọlá si
Jesu ti Nasareti lori: ẹniti o nkiri lati ṣe

Digitized by Google

ore, ati lati ṣe dida ara gbogbo awọn ti ara
kan fun Eṣu; nitori Ọlọrun wà pẹlu rẹ̀.
39 Awa si li ẹlẹri gbogbo ohun ti o ṣe,
ati ni ilẹ awọn Ju, ati ni Jerusalemu;
ẹniti nwọn pa, ti nwọn si fi há lori igi:
40 On li Ọlọrun jinde ni ijọ kẹta, o si fi
i hàn nigbangba;
41 Koṣepe fun gbogbo enia, bikoṣe fun
awọn ẹlẹri ti a ti yàn tẹlẹ lati ọdọ Ọlọrun
wá, fun awa, ti awa ba a jẹ, ti awa si ba a
mu lẹhin igbati o jinde kuro ninu okú.
42 O si rán wa lọ iwasu fun awọn enia,
ati lati jẹri pe, on li a yàn lati ọdọ Ọlọrun
ṣe Onidajọ ãye on okú.
43 On ni gbogbo awọn woli jẹri fun pe,
ẹnikẹni ti o ba gbagbọ́ li orukọ rẹ̀, yio ri
imukuro ẹ̀ṣẹ gbà.
44 ¶ Bi Peteru si ti nsọ̀rọ wọnyi li ẹnu,
Ẹmí Mimọ́ bà le gbogbo awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ
na.
45 Hà si ṣe awọn onilà ti o gbagbọ́, iwọn
awọn ti o ba Peteru wá, nitoriti ẹ̀bun Ẹmí
Mimọ́ dà lu awọn Keferi pẹlu.
46 Nitori nwọn gbọ́, nwọn nfi ède miran
fọ̀, nwọn si nyin Ọlọrun logo. Nigbana
ni Peteru dahùn wipe,
47 Ẹnikẹni le sofin omi, ki a má fi bap-
tisi awọn wọnyi, ti nwọn gbà Ẹmí Mimọ́
gẹgẹ bi awa?
48 O si ni ki a baptisi wọn li orukọ
Oluwa. Nigbana ni nwọn bẹ̀ ẹ ki o duro
ni ijọ melokan.

## ORI 11.

ATI awọn aposteli ati awọn arakọnrin ti
o wà ni Judea gbọ́ pe awọn Keferi
pẹlu ti gbà ọ̀rọ Ọlọrun.
2 Nigbati Peteru si gòke wá si Jerusa-
lemu, awọn onilà mba a sọ̀,
3 Wipe, Iwọ tọ̀ awọn enia alaikọlà lọ, o
si ba wọn jẹun.
4 Ṣugbọn Peteru bẹ̀rẹ si irohin lati ipi-
lẹṣẹ, o si tò o fun wọn lẹsẹsẹ, wipe,
5 Mo wà ni ilu Joppa emi ngbadura: li
ojuran mo ri iran kan, Ohun-ilo kan sọ-
kalẹ bi gọgọwu nla, ti a so leti igun
mẹrẹrin, o nsọkalẹ ti ọrun bọ̀; o si wá titi
o fi de ọdọ mi:
6 Ohun ti mo tẹjumọ́, ti mo fiyesi, mo
si ri ẹran ẹlẹsẹ mẹrin aiye yi, ati ẹranko
igbẹ́, ati ohun ti nrakò, ati ẹiyẹ oju ọrun.
7 Mo si gbọ́ ohùn kan ti o fọ̀ si mi pe,
Dide, Peteru; mã pa, ki o si mã jẹ.
8 Ṣugbọn mo dahùn wipe, Bẹ̃kọ, Olu-
wa: nitoriti kò si nkan èwọ tabi alaimọ́
ti o wọ̀ mi li ẹnu nigba kan ri lai.
9 Ṣugbọn ohùn na tún fọ̀ si mi lati ọrun
wá pe, Ohun ti Ọlọrun ba ti wẹ̀nu, iwọ
máṣe pè li èwọ.
10 Eyiyi si ṣe bẹ̃ li ẹrinmẹta: gbogbo
rẹ̀ si fà pada lọ soke ọrun.
11 Si wo o, lojukanna ọkọnrin mẹta ti
de eti ile ti mo gbé wà, ti a rán ti Kesarea
si mi.
12 Ẹmí si wi fun mi pe, ki emi ki o mã
ba wọn lọ, ki emi máṣe kọnnu ohunkohun.
Pẹlupẹlu awọn arakọnrin mẹfa wọnyi si ba
mi lọ, awa si wọ̀ ile ọkọnrin na:
13 O si sọ fun wa bi on ti ri angeli kan
ni ile rẹ̀, ti o duro, ti o si wi fun u pe,
Ranṣẹ lọ si Joppa, ki o si pè Simoni ti
apele rẹ̀ jẹ Peteru;
14 Ẹniti yio sọ ọ̀rọ fun ọ, bi a o ti gbà
ọ ati gbogbo ara ile rẹ là.
15 Bi mo si ti bẹ̀rẹ si isọ, Ẹmí Mimọ́ si
bà le wọn, gẹgẹ bi o ti bà le wa li àtete-
kọṣe.
16 Nigbana ni mo ranti ọ̀rọ Oluwa, bi
o ti wi pe, Johannu fi omi baptisi nitõtọ;
ṣugbọn a o fi Ẹmí Mimọ́ baptisi nyin.
17 Njẹ gẹgẹ bi Ọlọrun si ti bùn wọn ni
irú ẹ̀bun ti o fifun awa ti o gbà Jesu Kristi
Oluwa gbọ́; tali emi ti emi o fi dè Ọlọrun
li ọ̀na?
18 Nigbati nwọn si gbọ́ nkan wọnyi,
nwọn si pa ẹnu wọn mọ́, nwọn si yin Ọlọ-
run logo wipe, Njẹ Ọlọrun fi ironupiwada
si iye fun awọn Keferi pẹlu.
19 ¶ Awọn ti o si tuka kiri niti inuni-
bini ti o ṣẹ̀ nipa ti Stefanu, nwọn rin de to
bi Fenike, ati Kipru, ati Antioku, nwọn kò
wasu ọ̀rọ na fun ẹlomiran, bikoṣe fun kiki
awọn Ju.
20 Ati awọn ẹlomiran ti iṣe ara Kipru,
ati Kirene, nigbati nwọn de Antioku awọn
ẹniti o sọ̀rọ fun awọn ara Hellene, nwọn
nwasu Jesu Oluwa.
21 Ọwọ́ Oluwa si wà pẹlu wọn: iye
awọn enia pipọ si gbagbọ́, nwọn si yipada
si Oluwa.
22 ¶ Nigbana ni ihin nkan wọnyi de etí
ijọ ti o wà ni Jerusalemu: nwọn si rán
Barnaba, ki o lọ to bi Antioku.
23 Nigbati o si de ibẹ̀, ẹniti o si ri ore-
ọfẹ Ọlọrun, o yọ̀, o si gbà gbogbo wọn
niyanju pe, pẹlu ipinnu li ọkàn ni ki nwọn
ki o fi ara mọ́ Oluwa.
24 Nitori on ṣe enia rere, o si kún fun
Ẹmí Mimọ́, ati fun igbagbọ́: enia pipọ li
a si kà kún Oluwa.
25 Barnaba si dide, o lọ si Tarsu lati wá
Saulu.

Digitized by Google

26 Nigbati o si ri i, o mu u wá si Antioku. O si ṣe, o kadun kan gbako ti nwọn mba ijọ pejọ pọ̀, nwọn si kọ́ enia pipọ. Ni Antioku ni nwọn gbé tètekọ pè awọn ọmọ-ẹhin ni Krist:an.

27 ¶ Li ọjọ wọnni li awọn woli si ti Jerusalemu sọkalẹ wá si Antioku.

28 Nigbati ọkan ninu wọn, ti a npè ni Agabu si dide, o sọtẹlẹ nipa ẹmí pe, ìyan nla yio mu ká gbogbo aiye: ti o si ṣẹ nigba ọjọ Klaudiu Kesari.

29 Nigbana li awọn ọmọ-ẹhin pinnu rẹ̀, olukuluku bi agbara rẹ̀ ti mọ, lati rán iranlọwọ si awọn arakọnrin ti o wà ni Judea:

30 Ti nwọn si ṣe, nwọn si rán a lọ si awọn alàgba li ọwọ́ Barnaba on Saulu.

## ORI 12.

LI akokò igbana ni Herodu ọba si nawọ́ rẹ̀ lati tọ́ awọn kan ninu ijọ.

2 O si fi idà bẹ́ Jakọbu arakọnrin Johannu lori.

3 Nigbati o si ri i pe, o dùnmọ awọn Ju, o si nawọ́ mu Peteru pẹlu. Nigbana li ọjọ aiwukara.

4 Nigbati o si mu u, o fi i sinu tubu, o fi i le ori ẹṣọ́ mẹrin awọn ọmọ-ogun lọwọ lati ma ṣọ ọ; o nrò pe lẹhin Irekọja, ki on ki o mu u jade tọ̀ awọn enia wá.

5 Njẹ nwọn pa Peteru mọ́ ninu tubu: ṣugbọn ijọ ngbadura fun u li aisimi si Ọlọrun.

6 Nigbati Herodu iba si mu u jade, li oru na Peteru nsùn li arin awọn ọmọ-ogun meji ninu ìde ẹ̀wọn meji: awọn ọmọ-ogun si wà niwaju ilẹkun, nwọn nṣọ tubu na.

7 Si kiyesi i, angeli Oluwa duro tì i, imọlẹ si mọ́ ninu tubu: nigbati o si lù Peteru pẹ́pẹ li ẹgbẹ o ji i, o ni, Dide kánkan. Ẹ̀wọn rẹ̀ si bọ́ silẹ kuro lọwọ rẹ̀.

8 Angeli na si wi fun u pe, Di àmure, ki o si so salubata rẹ. O si ṣe bẹ̃. O si wi fun u pe, Da aṣọ rẹ bora, ki o si mã tọ̀ mi lẹhin.

9 On si jade, o tọ̀ ọ lẹhin; kò si mọ̀ pe otitọ li ohun na ṣe lati ọwọ́ angeli na wá; ṣugbọn o ṣebi on wà li ojuran.

10 Nigbati nwọn kọja iṣọ kini ati keji, nwọn de ẹnu-ọ̀na ilẹkun irin, ti o lọ si ilu; ti o si tikararẹ̀ ṣí silẹ fun wọn: nigbati nwọn si jade, nwọn nlọ titi li ọ̀na igboro kan; lojukanna angeli na si fi i silẹ lọ.

11 Nigbati oju Peteru si walẹ, o ni, Nigbayi ni mo to mọ̀ nitõtọ pe, Oluwa rán angeli rẹ̀, o si gbà mi li ọwọ́ Herodu, ati ninu gbogbo ireti awọn enia Ju.

12 Nigbati o si rò o, o lọ si ile Maria iya Johannu, ti apele rẹ̀ jẹ Marku; nibiti awọn enia pipọ pejọ si, ti nwọn ngbadura.

13 Bi Peteru si ti kànkun, ọmọbirin kan ti a npè ni Roda, o wá bère.

14 Nigbati o si ti mọ̀ ohùn Peteru, on kò ṣí ilẹkun nitori ayọ̀, ṣugbọn o sure wọle, o si wi fun wọn pe, Peteru duro niwaju ilẹkun.

15 Nwọn si wi fun u pe, Iwọ nṣiwere. Ṣugbọn o tẹnumọ́ ọ gidigidi pe bẹ̃ni. Nwọn si wi pe, Angeli rẹ̀ ni.

16 Ṣugbọn Peteru duro o nkànkun, nigbati nwọn si ṣí ilẹkun, ti nwọn si ri i, ẹnu yà wọn.

17 Ṣugbọn o njuwọ́ si wọn ki nwọn ki o dakẹ, o sọ idi rẹ̀ gbogbo fun wọn bi Oluwa ti mu on jade kuro ninu tubu. O si wipe, Ẹ lọ, ẹ si ròhin nkan wọnyi fun Jakọbu, ati fun awọn arakọnrin. Nigbati o si jade, o lọ si ibomiran.

18 Bi o si ti di owurọ̀, irú diẹ ki o wà ninu awọn ọmọ-ogun, nibo ni Peteru gbé wà.

19 Nigbati Herodu si wá a kiri, ti kò si ri i, o wádi awọn oluṣọ, o ni, ki a pa wọn. O si sọkalẹ lati Judea lọ si Kesarea, o joko nibẹ̀.

20 ¶ Herodu si mbinu ijà si awọn ará Tire on Sidoni gidigidi: ṣugbọn nwọn fi ọkàn kan wá sọdọ rẹ̀, nigbati nwọn si fi Blastu iwẹfa ọba ṣe ọrẹ́, nwọn nfẹ ìlaja; nitori ati ilu ọba lọ li a ti mbọ́ ilu wọn.

21 O si di ọjọ afiyesi kan, ni Herodu gunwà, o joko lori itẹ́, o nsọ ọ̀rọ fun wọn.

22 Awọn enia si hó kùhu, wipe, Ohùn ọlọrun ni kì iṣe ti enia.

23 Lojukanna angeli Oluwa lù u, nitoriti kò fi ogo fun Ọlọrun: idin si jẹ ẹ, o si ku.

24 ¶ Ṣugbọn ọ̀rọ Ọlọrun gbilẹ, o si bi si i.

25 Barnaba on Saulu si pada ti Jerusalemu wá, nigbati nwọn pé ọjọ iṣẹ iranṣẹ wọn, nwọn si mu Johannu wá pẹlu wọn, apele ẹniti ijẹ Marku.

## ORI 13.

AWỌN woli ati awọn olukọni kan si wà ninu ijọ ti o wà ni Antioku; bi Barnaba, ati Simeoni ti a npè ni Nigeri, ati Lukiu ara Kirene, ati Manaeni, ti a tọ́ pọ̀ pẹlu Herodu tetrarki, ati Saulu.

2 Bi nwọn si ti njọsìn fun Oluwa, ti nwọn si ngbàwẹ, Ẹmí Mimọ́ wipe, Ẹ yà

Digitized by Google

Barnaba on Saulu fun mi si iṣẹ ti mo ti pè
wọn si.
3 Nigbati nwọn si ti gbàwẹ, ti nwọn si
gbadura, nwọn fi ọwọ́ le wọn, nwọn si rán
wọn lọ.
4 ¶ Bi a ti rán wọn lati ọwọ́ Ẹmí Mimọ́
lọ, bẹ̃ni nwọn sọkalẹ lọ si Seleukia; lati
ibẹ̀ lọ nwọn si wọkọ̀ lọ si Kipru.
5 Nigbati nwọn si wà ni Salami, nwọn
wasu ọ̀rọ Ọlọrun ni sinagogu awọn Ju:
nwọn si ni Johannu pẹlu fun iranṣẹ wọn.
6 Nigbati nwọn si là adádó na já de
Pafo, nwọn ri oṣó kan, woli eke, Ju, ti a
npè ní Barjesu:
7 Ẹniti o ti wà lọdọ Sergiu Paulu bãlẹ
ilu na, amoye enia; ẹniti o ranṣẹ pè Bar-
naba on Saulu, o si nfẹ gbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun.
8 Ṣugbọn Elima oṣó na (bẹ̃ni itumọ̀ oru-
kọ rẹ̀) o dè wọn lọ̀na, o nfẹ pa bãlẹ ni iyè
dà kuro ni igbagbọ́.
9 Ṣugbọn Saulu (ti a si npè ni Paulu,) o
kún fun Ẹmí Mimọ́, nigbati o si tẹjumọ́ ọ,
10 O ni, Iwọ, ọmọ Èṣu, iwọ, ọtá ododo
gbogbo, ẹniti o kún fun arekereke gbogbo,
ati fun ìka gbogbo, iwọ kì yio dẹkun ọ̀na
otitọ Oluwa iyipo?
11 Njẹ nisisiyi, wo o, ọwọ́ Oluwa mbẹ
lara rẹ, iwọ o si fọju, lairi õrùn ni sã kan.
Lojukanna owusuwusu ati òkunkun si bò
o; o si nwá enia kiri lati fà a lọwọ lọ.
12 Nigbati bãlẹ ri ohun ti o ṣe, o gba-
gbọ́, hà si nṣe e si ẹkọ́ Oluwa.
13 Nigbati Paulu ati awọn ti o wà pẹlu
rẹ̀ si ṣikọ̀ ni Pafo, nwọn wá si Perga ni
Pamfilia: Johannu si fi wọn silẹ, o si pada
lọ si Jerusalemu.
14 ¶ Nigbati nwọn si jade kuro ni
Perga, nwọn wá si Antioku ni Pisidia,
nwọn si wọ̀ inu sinagogu li ọjọ isimi, nwọn
si joko.
15 Lẹhin kika iwe ofin ati iwe awọn
woli, awọn olori sinagogu ranṣẹ si wọn,
wipe, Alàgba, ará, bi ẹnyin ba li ọ̀rọ-kọrọ
iyanju fun awọn enia, ẹ wi.
16 Paulu si dide duro, o si juwọ́ si wọn,
o ni, Ẹnyin ọkọnrin Israeli, ati ẹnyin ti o
bẹru Ọlọrun, ẹ fi etí silẹ.
17 Ọlọrun awọn enia Israeli yi, on li o
yàn awọn baba wa, o si gbé awọn enia na
leke, nigbati nwọn wà li atipo ni ilẹ Egipti,
apá nla li o si fi mu wọn jade kuro ninu rẹ̀.
18 Ni ìwọn igba ogoji ọdún li o fi mu
sũru fun ìwa wọn ni ijù.
19 Nigbati o si run orilẹ-ède meje ni ilẹ
Kenaani, o si pín ilẹ wọn fun wọn.
20 Lẹhin eyini, li akokò ìwọn adọta le
ni irinwo ọdún, o fi onidajọ fun wọn, titi o
fi di igba Samueli woli.
21 Lẹhinna ni nwọn bère ọba kan:
Ọlọrun si fun wọn ni Saulu ọmọ Kisi,
ọkọnrin kan ninu ẹ̀ya Benjamini, li ogoji
ọdún.
22 Nigbati o si ṣí i nipò kuro, o gbé
Dafidi dide li ọba wọn; ẹniti o si jẹri fun
pe, Mo ri Dafidi ọmọ Jesse ẹni ọkàn mi, ti
yio mu gbogbo ifẹ mi ṣẹ.
23 Ninu iru-ọmọ ọkọnrin yi, ni Ọlọrun
ti gbe Jesu Olugbala dide fun Israeli gẹgẹ
bi ileri.
24 Nigbati Johannu ti tèteko wasu
baptismu ironupiwada fun gbogbo enia
Israeli ṣaju wíwa rẹ̀.
25 Bi Johannu si ti là ipa ti rẹ̀ já, ó ni,
Tali ẹnyin ṣebi emi iṣe? Emi kì iṣe on.
Ṣugbọn ẹ kiyesi i, ọkan mbọ̀ lẹhin mi, bàta
ẹsẹ ẹniti emi kò to itú.
26 Alàgba, ará, awọn ọmọ kukuté Abra-
hamu, ati ẹnikẹni ninu nyin ti o bẹru
Ọlọrun, ẹnyin li a rán ọ̀rọ igbala yi si.
27 Nitori awọn ara Jerusalemu, ati awọn
olori wọn, nitoriti nwọn kò mọ̀ ọ, ati ède
awọn woli, ti a nkà li ọjọjọ isimi kò yé
wọn, nwọn mu wọn ṣẹ ni didajọ rẹ̀ Ièbi.
28 Ati bi nwọn kò tilẹ ti ri idi ohun
ikú lara rẹ̀, ṣugbọn nwọn rọ̀ Pilatu lati
pa a.
29 Bi nwọn si ti mu nkan gbogbo ṣẹ ti
a ti kọwe nitori rẹ̀, nwọn si sọ̀ ọ kalẹ kuro
lori igi, nwọn si tẹ́ ẹ si iboji okuta.
30 Ṣugbọn Ọlọrun jí i dide kuro ninu
okú:
31 A si ri i li ọjọ pipọ ninu awọn ti o ba
a gòke lati Galili wá si Jerusalemu, ẹniti
nṣe ẹlẹri rẹ̀ fun awọn enia.
32 Awa si nròhin ayọ̀ fun nyin, bi ileri
ti a ti ṣe fun awọn baba wa,
33 Bi Ọlọrun ti mu eyi na ṣẹ fun awa
ọmọ wọn, nigbati o ji Jesu dide; bi a si ti
kọwe rẹ̀ pẹlu ninu Psalmu keji pe, Iwọ li
Ọmọ mi, loni ni mo bí ọ.
34 Ati niti pe o ji i dide kuro ninu oku,
ẹniti kì yio tun pada si ibajẹ mọ, o wi bayi
pe, Emi o fun nyin ni ore mimọ́ Dafidi, ti
o daju.
35 Nitori o si wi ninu Psalmu miran
pẹlu pe, Iwọ kì yio jẹ ki Ẹni Mimọ́ rẹ ki o
dibajẹ.
36 Nitori lẹhin igba ti Dafidi sìn iran
rẹ̀ tan bi ìfẹ Ọlọrun, o sùn, a si tẹ́ ẹ le
awọn baba rẹ̀, o si dibajẹ:
37 Ṣugbọn ẹniti Ọlọrun jinde kò dibajẹ.
38 ¶ Njẹ ki o yé nyin, alàgba, ará, pe

Digitized by Google

nipasẹ ọkọnrin yi li a nwasu idariji ẹ̀ṣẹ fun nyin:

39 Ati ninu rẹ̀ a dare fun gbogbo awọn ti o gbagbọ́ ninu ohun gbogbo, ti a kò le dá nyin lare ninu ofin Mose.

40 Nitorina ẹ kiyesi ara, ki eyini ki o máṣe de si nyin, ti a ti sọ ninu iwe awọn woli pe;

41 Wò o, ẹnyin ẹlẹgàn, ki hà ki o ṣe nyin, ki ẹnyin ki o si fò lọ: nitoriti mo ṣe iṣẹ li ọjọ nyin, iṣẹ ti ẹnyin kò jẹ gbagbọ́ bi enia tilẹ sọdi rẹ̀ fun nyin.

42 Nigbati awọn Ju jade kuro ninu sinagogu, awọn Keferi bẹ̀bẹ ki a wasu ọ̀rọ wọnyi fun wọn li ọjọ isimi keji.

43 Nigbati ijọ si tuka, ọ̀pọ ninu awọn Ju ati awọn olufọkansin ninu awọn alawọṣe tọ̀ Paulu on Barnaba lọ: ti nwọn si sọ̀rọ fun wọn, nwọn nyi wọn li ọkàn pada lati duro ninu ore-ọfẹ Ọlọrun.

44 ¶ Li ọjọ isimi keji, gbogbo ilu si fẹrẹ pejọ tan lati gbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun.

45 Ṣugbọn nigbati awọn Ju ri ọ̀pọ enia, inu wọn kún fun irira, nwọn nsọ̀rọ òdi si nkan ti nti ẹnu Paulu jade, nwọn nja a ni koro, nwọn si nsọ ọ̀rọ buburu.

46 Paulu on Barnaba si mu ọkàn le, nwọn ni, O tọ́ lati tètekọ sọ ọ̀rọ Ọlọrun fun nyin: ṣugbọn ẹ kiyesi i, ẹnyin ti ta a nù kuro lọdọ nyin, ẹnyin si ti ṣe idajọ ara nyin pe ẹnyin kò si yẹ si iye ti kò nipẹkun, wò o, awa yipada sọdọ awọn Keferi.

47 Bẹ̃li Oluwa sá ti wi fun wa pe, Mo ti gbé ọ kalẹ ṣe imọlẹ fun awọn Keferi, ki iwọ ki o le ma wà fun igbala titi de opin aiye.

48 Nigbati awọn Keferi si gbọ́ eyi, nwọn yọ̀, nwọn si yin ọ̀rọ Oluwa logo: ati iwọn awọn ti a làna si iye ti kò nipẹkun, nwọn gbagbọ́.

49 A si tàn ọ̀rọ Oluwa kalẹ ni gbogbo ẹkùn na.

50 Ṣugbọn awọn Ju rú awọn obirin rere ọlọlá, ati awọn àgba ilu na soke, nwọn si da inunibini silẹ si Paulu on Barnaba, nwọn si ṣí wọn kuro li àgbegbe wọn.

51 Ṣugbọn nwọn gbọ̀n ekuru ẹsẹ wọn si wọn, nwọn si lọ si Ikonioni.

52 Awọn ọmọ-ẹhin si kún fun ayọ̀ ati fun Ẹmí Mimọ́.

## ORI 14.

OSI ṣe, ni Ikonioni, awọn mejeji jumọ wọ̀ inu sinagogu awọn Ju lọ, nwọn si sọ tobẹ̃, ti ọ̀pọ enia ati awọn Ju, ati awọn Hellene pẹlu gbagbọ́.

2 Ṣugbọn awọn alaigbagbọ́ Ju rú awọn Keferi soke, nwọn si bà wọn ninu jẹ si awọn arakọnrin na.

3 Njẹ nigba pipẹ ni nwọn fi wà nibẹ̀, ti nwọn nsọ li aibẹ̀ru nipa ti Oluwa, ẹniti o jẹri si ọ̀rọ ore-ọfẹ rẹ̀, ti o si mu iṣẹ àmi ati iṣẹ iyanu ṣẹ li ọwọ́ wọn.

4 Ṣugbọn ijọ enia ilu na si yapa si ara wọn: apakan si dàpọ mọ́ awọn Ju, apakan si dàpọ mọ́ awọn aposteli.

5 Bi awọn Keferi, ati awọn Ju pẹlu awọn olori wọn ti npete ati kọlù wọn lati ṣe wọn ni jamba, ati lati sọ wọn li okuta,

6 Nwọn mọ̀, nwọn si sá lọ si Listra ati Derbe ilu Likaonia, ati si àgbegbe ti o yiká kiri:

7 Nibẹ̀ ni nwọn si wasu ihin-rere.

8 ¶ Ọkọnrin kan ti o rọ li ẹsẹ rẹ̀, ẹniti o ti ya arọ lati inu iya rẹ̀ wá, ti kò rin ri, o wà ni Listra:

9 On na li o gbọ́ Paulu nsọ̀rọ: nigbati o tẹjumọ́ ọ, ti o si ri pe, o ni igbagbọ́ lati mu u lara da,

10 O wi fun u li ohùn rara pe, Dide duro ṣanṣan li ẹsẹ rẹ. O si fò, o si rin.

11 Nigbati awọn enia si ri ohun ti Paulu ṣe, nwọn gbé ohùn wọn soke li ède Likaonia, wipe, Awọn ọlọrun tọ̀ wa wá li àwọ enia.

12 Nwọn si pè Barnaba ni Seusi (Jupiteri;) ati Paulu ni Herme (Merkuriu,) nitori on li olori ọ̀rọ isọ.

13 Alufa Jupiteri, ti o wà niwaju ilu wọn, si mu malu titẹ̀, ati màriwo wá si ẹnu-ọ̀na, on iba si rubọ pẹlu awọn enia.

14 Ṣugbọn nigbati awọn aposteli Barnaba on Paulu gbọ́, nwọn fà aṣọ wọn ya, nwọn si sure lọ sinu awujọ, nwọn nke,

15 Nwọn si nwipe, Alàgba, ẽṣe ti ẹnyin fi nṣe nkan wọnyi? Enia oniru iwa kanna bi ẹnyin li awa, ti awa si nwasu ihin-rere fun nyin, ki ẹnyin ki o le yipada kuro ninu ohun asan wọnyi si Ọlọrun alãye, ti o da ọrun on aiye, ati okun, ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu wọn:

16 Ẹniti o ti jọwọ gbogbo orilẹ-ède nigbani, lati ma rin ni ipa ti wọn.

17 Ṣugbọn ko fi ara rẹ̀ silẹ li ailẹri, ni ti o nṣe rere, o nfun wa li òjo lati ọrun wá, ati akokò eso ọ̀pọlọpọ, o nfi onjẹ ati ayọ̀ kún wa ni inu.

18 Diẹ li o kù ki nwọn ki o ma le fi ọ̀rọ yi da awọn enia duro, ki nwọn ki o máṣe rubọ bọ wọn.

19 ¶ Awọn Ju kan ti Antioku ati Ikonioni wá, ti nwọn yi awọn enia li ọkàn

Digitized by Google

pada, nigbati nwọn si sọ Paulu li okuta,
nwọn wọ́ ọ jade kuro ni ilu na, nwọn ṣebi
o ti kú.
20 Ṣugbọn nigbati awọn ọmọ-ẹhin duro
tì i yiká, o dide, o wọ̀ ilu na lọ: o si di ijọ
keji o ba Barnaba lọ si Derbe.
21 Nigbati nwọn si wasu ihin-rere fun
awọn ara ilu na, ti nwọn si kọ́ ọ̀pọ enia,
nwọn tún pada lọ si Listra, ati Ikonioni,
ati si Antioku,
22 Nwọn nmu awọn ọmọ-ẹhin li ọkàn
le, nwọn ngbà wọn niyanju lati duro ni
igbagbọ́, ati pe ninu ipọnju pipọ li awa o
fi de ijọba Ọlọrun.
23 Nigbati nwọn si yàn awọn alàgba si
olukuluku ijọ, ti nwọn si fi àwẹ gbadura,
nwọn fi wọn le Oluwa lọwọ, ẹniti nwọn
gbagbọ́.
24 Nigbati nwọn si là Pisidia já, nwọn
wá si Pamfilia.
25 Nigbati nwọn si wasu ọ̀rọ na ni Perga,
nwọn sọkalẹ wá si Atalia:
26 Lati ibẹ̀ lọ ni nwọn ba ti ọkọ̀ lọ si
Antioku, nibi ti a gbé ti fi wọn le ore-ọfẹ
Ọlọrun lọwọ, nitori iṣẹ ti nwọn ṣe pari.
27 Nigbati nwọn si de, ti nwọn si pè ijọ
jọ, nwọn si ròhin gbogbo ohun ti Ọlọrun fi
wọn ṣe, ati bi o ti ṣí ilẹkun igbagbọ́ silẹ
fun awọn Keferi.
28 Nwọn si ba awọn ọmọ-ẹhin gbé nibẹ̀
nigba pipẹ.

## ORI 15.

AWỌN ọkọnrin kan ti nwọn ti Judea
sọkalẹ wá, nwọn kọ́ awọn arakọnrin
pe, Bikoṣepe a ba kọ nyin ni ilà nipa iṣe
Mose, ẹnyin kì yio le là.
2 Njẹ nigbati iyapa ti o wà ati iyàn ti
Paulu on Barnaba mba wọn jà kò si mọ̀ ni
ìwọn, nwọn pinnu rẹ̀ lati rán Paulu on
Barnaba, ati awọn kan miran ninu wọn,
tọ̀ awọn aposteli ati awọn alàgba lọ ni
Jerusalemu nitori ọ̀ran yi.
3 Nigbati a si ti fi ẹsẹ wọn le ọ̀na lati
ọdọ ijọ wá, nwọn kọja larin Fenike on
Samaria, nwọn nròhin iyipada awọn Ke-
feri: nwọn si fi ayọ̀ nla fun gbogbo awọn
arakọnrin.
4 Nigbati nwọn si de Jerusalemu, atẹ-
wọgbà ni nwọn lọdọ ijọ, ati awọn aposteli,
ati awọn alàgba, nwọn si ròhin ohun gbo-
gbo ti Ọlọrun ti fi wọn ṣe.
5 Ṣugbọn awọn kan ni ipa ti awọn Farisi
ti nwọn gbagbọ́ dide, nwọn nwipe, O tọ́
lati kọ wọn ni ilà, ati lati paṣẹ fun wọn
pe ki nwọn kí o mã pa ofin Mose mọ́.
6 ¶ Ati awọn aposteli ati awọn alàgba
pejọ lati gbìmọ ọ̀ran yi.
7 Nigbati iyan si di pipọ, Peteru dide,
o si wi fun wọn pe, Alàgba, ará, ẹnyin mọ̀
nigba atijọ, bi Ọlọrun ti yàn ninu wa, ki
awọn Keferi ki o le gbọ́ ọ̀rọ ihin-rere li ẹnu
mi, ki nwọn si gbagbọ́.
8 Ati Ọlọrun, ti iṣe olumọ ọkàn, o gbà
wọn li ẹrí jẹ, o nfun wọn li Ẹmí Mimọ́,
gẹgẹ bi awa;
9 Kò si yà awa ati awọn sọ̀tọ, o nfi
igbagbọ́ wẹ̀ wọn li ọkàn mọ́.
10 Njẹ nitorina ẽṣe ti ẹnyin o fi dán
Ọlọrun wò, lati fi àjaga bọ̀ awọn ọmọ-ẹhin
li ọrùn, eyiti awọn baba wa ati awa kò le
rù?
11 Ṣugbọn awa gbagbọ́ pe nipa ore-ọfẹ
Oluwa Jesu Kristi awa o là, gẹgẹ bi awọn.
12 ¶ Nigbana ni gbogbo ajọ dakẹ, nwọn
si fi etí si Barnaba on Paulu, ti nwọn
nròhin iṣẹ aṣẹ ati iṣẹ iyanu ti Ọlọrun ti fi
ọwọ́ wọn ṣe ninu awọn Keferi.
13 ¶ Lẹhin igbati nwọn si dakẹ, Jakọbu
dahùn, wipe, Alàgba, ará, ẹ fi etí si ti emi:
14 Simeoni ti wi bi Ọlọrun ti bojuwò li
àtetekọṣe, lati yàn enia ninu awọn Keferi
fun orukọ rẹ̀.
15 Ati eyiyi li ọ̀rọ awọn woli ba ṣe dede;
bi a ti kọwe rẹ̀ pe,
16 Lẹhin nkan wọnyi li emi o pada, emi
o si tún agọ́ Dafidi pa ti o ti wó lulẹ; emi
o si tún ahoro rẹ̀ kọ́, emi o si gbé e naró;
17 Ki awọn enia iyokù le ma wá Oluwa,
ati gbogbo awọn Keferi lara ẹniti a npè
orukọ mi, li Oluwa ti o ṣe gbogbo nkan
wọnyi wi.
18 Mimọ̀ fun Ọlọrun ni iṣẹ rẹ̀ gbogbo,
lati igba ọjọ ìwa.
19 Njẹ ìmọ temi ni, ki awa ki o máṣe
yọ awọn ti o yipada si Ọlọrun lẹnu ninu
awọn Keferi:
20 Bikoṣepe ki a kọwe si wọn, ki nwọn
ki o fà sẹhin kuro ninu ẽri ere, ati kuro
ninu àgbere, ati ki nwọn ki o kọ̀ ohun ilọ-
lọrun-pa, ati kuro ninu ẹ̀jẹ.
21 Mose sá li ẹni nigba atijọ ti nwasu
rẹ̀ ni ilu gbogbo, ama kà a ninu sinagogu
li ọjọjọ isimi.
22 Nigbana li o tọ́ loju awọn aposteli,
ati awọn alàgba, pẹlu gbogbo ijọ, lati yàn
ọkọnrin ninu wọn ranṣẹ si Antioku pẹlu
Paulu on Barnaba; Juda ti a npè apele rẹ̀
ni Barsaba, ati Sila, ẹniti o li orukọ ninu
awọn arakọnrin:
23 Nwọn si kọ iwe le wọn lọwọ bayi pe;
Awọn aposteli, ati awọn alàgbà, ati awọn

Digitized by Google

arakọnrin, nwọn kí awọn arakọnrin ti o
wà ni Antioku, ati ni Siria, ati ni Kilikia
ninu awọn Keferi:
24 Bi awa ti gbọ́ pe, awọn kan ti o ti
ọdọ wa jade lọ nfi ọ̀rọ bà nyin ninu jẹ, ti
nwọn nyi nyin li ọkàn po, wipe, Ẹnyin kò
gbọdọ ṣaima kọ ilà, ati ṣaima pa ofin Mose
mọ́: ẹniti awa kò fi irú ofinkofin nì le
lọwọ:
25 O yẹ loju awa, ti awa fi ọkàn kan
pejọ, ki a rán ọkọnrin ti o li orukọ si nyin
pẹlu Barnaba on Paulu awọn olufẹ wa,
26 Awọn ọkọnrin ti o fi ẹmí wọn wewu
nitori orukọ Oluwa wa Jesu Kristi.
27 Nitorina awa rán Juda on Sila, awọn
ti yio si fi ọ̀rọ ẹnu sọ ohun kanna fun nyin.
28 Nitoriti o si dara loju Ẹmí Mimọ́, ati
loju awa, ki awa ki o máṣe dì ẹrù kà nyin,
jù nkan ti a ko le ṣe alaiṣe wọnyi lọ;
29 Ki ẹnyin ki o fà sẹhin kuro nipa ẹran
apa bọ oriṣa, ati kuro ninu ẹ̀jẹ, ati ohun
ilọlọrunpa, ati kuro ninu àgbere: ninu
ohun ti, bi ẹnyin ba pa ara nyin mọ́ kuro,
ẹnyin o ṣe rere. Alafia fun nyin.
30 Nigbati nwọn si jọwọ wọn lọwọ lọ,
nwọn wá si Antioku: nigbati nwọn si pè
apejọ, nwọn fi iwe na fun wọn:
31 Nigbati nwọn si kà a, nwọn yọ̀ fun
itunu na.
32 Bi Juda on Sila tikara wọn ti ṣe woli
pẹlu, nwọn fi ọ̀rọ pipọ gbà awọn arakọnrin
niyanju, nwọn si mu wọn li ọkàn le.
33 Nigbati nwọn si pẹ diẹ, nwọn jọwọ
wọn lọwọ lati ọdọ awọn arakọnrin lọ li
alafia si ọdọ awọn aposteli.
34 Ṣugbọn o wù Sila lati gbé ibẹ̀ diẹ na.
35 Paulu on Barnaba si duro ni Antioku,
nwọn nkọ́ni, nwọn si nwasu ọ̀rọ Oluwa, ati
awọn pipọ miran pẹlu wọn.
36 ¶ Lẹhin ijọ melokan, Paulu si sọ fun
Barnaba pe, Jẹ ki a tún pada lọ ibẹ̀ awọn
arakọnrin wa wò, bi nwọn ti nṣe, ni ilu
gbogbo ti awa ti wasu ọ̀rọ Oluwa.
37 Barnaba si pinnu rẹ̀ lati mu Johannu
lọ pẹlu wọn, ẹniti apele rẹ̀ jẹ Marku.
38 Ṣugbọn Paulu rò pe, kò yẹ lati mu u
lọ pẹlu wọn, ẹniti o fi wọn silẹ ni Pamfilia,
ti kò si ba wọn lọ si iṣẹ na.
39 Ìja na si pọ̀ tobẹ̃, ti nwọn yà ara wọn
meji: nigbati Barnaba si mu Marku, o ba
ti ọkọ̀ lọ si Kipru;
40 Ṣugbọn Paulu yàn Sila, o si lọ, bi
ati fi i le ore-ọfẹ Ọlọrun lọwọ lati ọdọ awọn
arakọnrin.
41 O si là Siria on Kilikia lọ, o nmu ijọ
li ọkàn le.

## ORI 16.

NIGBANA li o si lọ si Derbe on Listra:
si kiyesi i, ọmọ-ẹhin kan wà nibẹ̀, ti
a npè ni Timoteu, ọmọ obirin kan ti iṣe
Ju, ti o gbagbọ́; ara Hellene ni baba rẹ̀:
2 Ihin rere ẹniti nwọn nsọ lọdọ awọn
arakọnrin ti o wà ni Listra ati Ikonioni.
3 On ni Paulu nfẹ mu lọ pẹlu rẹ̀; ni-
gbati o si mu u, o kọ ọ ni ilà, nitori awọn
Ju ti o wà li àgbegbe wọnni: nitori gbogbo
wọn li o mọ̀ pe, ara Hellene ni baba rẹ̀.
4 Bi nwọn si ti nlà arin ilu lọ, nwọn fi
ofin na fun wọn lati mã pa a mọ́, ti a ti
làna silẹ lati ọdọ awọn aposteli ati awọn
alàgba wá, ti o wà ni Jerusalemu.
5 Bẹ̃ni ijọ si fi ẹsẹ mulẹ ni igbagbọ́,
nwọn si npọ̀ si i lojojumọ.
6 Nigbati nwọn si là Frigia já, ati ẹkùn
Galatia, ti a ti ọdọ Ẹmí Mimọ́ kọ̀ fun wọn
lati wasu ọ̀rọ na ni Asia,
7 Nigbati nwọn de Misia, nwọn gbé e
wò lati lọ si Bitinia: ṣugbọn Ẹmí kò gbà
fun wọn.
8 Nigbati nwọn si kọja lẹba Misia, nwọn
sọkalẹ lọ si Troa.
9 Iran kan si hàn si Paulu li oru;
Ọkọnrin kan ara Makedonia duro, o si
mbẹ̀ ẹ, wipe, Rekọja wá si Makedonia, ki
o si ràn wa lọwọ.
10 Nigbati o si ti ri iran na, ọgan awa
ti mura ati lọ si Makedonia, a rò o tan pe,
Oluwa li o pè wa lọ lati wasu ihin-rere fun
wọn.
11 Njẹ nigbati awa si ṣikọ̀ ni Troa, awa
ba ọ̀na ganran wá si Samotrakia, ati ni ijọ
keji awa de Neapoli;
12 Lati ibẹ̀ awa si lọ si Filippi, ti iṣe
olú ilu ìha ibẹ̀ ni Makedonia, ati igberiko:
awa si wà ni ilu na, awa joko nibẹ̀ ni ijọ
melokan.
13 Nigbati o si di ọjọ isimi, awa jade lọ
si ẹhin ilu na, lẹba odò kan, nibiti nwọn
gbé ma gbadura; nigbati awa si joko, awa
ba awọn obirin ti ijumọ lọ sibẹ̀ sọrọ.
14 ¶ Ati obirin kan orukọ rẹ̀ aina jẹ
Lidia, elesè àluko, ara ilu Tiatira, ẹniti o
nsìn Ọlọrun, o gbọ́ ọ̀rọ wa: àiya ẹniti Olu-
wa ṣí, ti o fi etí si ohun ti a nsọ li ẹnu
Paulu.
15 Nigbati a si baptisi rẹ̀, ati awọn ará
ile rẹ̀, o bẹ̀ wa, wipe, Bi ẹnyin ba fi mi pè
olõtọ si Oluwa, ẹ wá si ile mi, ki ẹ si wọ̀
nibẹ̀. O si rọ̀ wa.
16 ¶ O si ṣe, bi awa ti nlọ si ile adura,
ọmọbirin kan ti o li ẹmí afọṣẹ, o pade wa,

Digitized by Google

ẹniti o fi afọṣẹ mu ère pipọ fun awọn oluwa
rẹ̀ wá:
17 On na li o ntọ̀ Paulu ati awa lẹhin, o
si nkigbe, wipe, Awọn ọkọnrin wọnyi ni
iranṣẹ Ọlọrun Ọgá-ogo, ti nfi ọ̀na igbala
hàn fun wa.
18 O si ṣe eyi li ọjọ pipọ. Nigbati inu
Paulu si bajẹ, o si yipada, o wi fun ẹmí na
pe, Mo wi fun ọ li orukọ Jesu Kristi ki iwọ
ki o jade lara rẹ̀. O si jade ni wakati
kanna.
19 ¶ Nigbati awọn oluwa rẹ̀ si ri pe,
igbẹkẹle ère wọn run, nwọn mu Paulu on
Sila, nwọn si wọ́ wọn lọ si ọjà tọ̀ awọn ijò-
ye lọ.
20 Nigbati nwọn si mu wọn tọ̀ awọn
olori lọ, nwọn ni, Awọn ọkọnrin wọnyi ti
iṣe Ju, nwọn ntó ilu wa jọjọ,
21 Nwọn si nkọ́ iṣe ti kò yẹ fun wa,
ẹniti iṣe ara Romu, lati gbà ṣe, ati lati
fiyesi.
22 Ijọ enia si duro pọ̀ tì wọn: nigbati
awọn olori si fà wọn li aṣọ ya, nwọn ni, ki
nwọn ki o lù wọn.
23 Nigbati nwọn si nà wọn ni ìna pipọ,
nwọn fi wọn sinu tubu, nwọn kìlọ fun oni-
tubu ki o pa wọn mọ́ rere:
24 Nigbati o gbọ́ irú ìlọ bẽ, ẹniti o tì
wọn sinu tubu ti inu lọhun, o si kàn àba
mọ ẹsẹ wọn.
25 ¶ Larin ọganjọ Paulu on Sila gbadu-
ra, nwọn si kọrin iyìn si Ọlọrun: awọn
ara-tubu si gburó wọn.
26 Lojukanna isẹlẹ nla si sẹ̀, tobẽ ti ipilẹ
ile tubu mì-titi: ọgan gbogbo ilẹkun si ti
ṣí, gbogbo ìde olukuluku si da silẹ.
27 Nigbati onitubu tají, ti o si ri pe,
awọn ilẹkun ile tubu ti ṣí silẹ, o fà idà rẹ̀
yọ, on iba si pa ara rẹ̀, o ṣebi awọn ara-
tubu ti sá lọ.
28 Ṣugbọn Paulu kọ kará, wipe, Máṣe
pa ara rẹ lara: nitori gbogbo wa mbẹ ni-
hinyi.
29 Nigbati o si pè iná, o bẹ́ sinu ile, o
nwariri, o wolẹ niwaju Paulu on Sila,
30 O si mu wọn jade, o ni, Alàgba, kini
ki emi ki o ṣe lati là?
31 Nwọn si wi fun u pe, Gbà Jesu Kristi
Oluwa gbọ́, iwọ o là ati awọn ará ile rẹ
pẹlu.
32 Nwọn si sọ ọ̀rọ Oluwa fun u, ati fun
gbogbo awọn ará ile rẹ̀.
33 O si mu wọn ni wakati na li oru, o
wẹ̀ ìna wọn; a si baptisi rẹ̀, ati gbogbo
awọn ará ile rẹ̀ lojukanna.
34 Nigbati o si mu wọn wá si ile rẹ̀, o
gbé onjẹ kalẹ niwaju wọn, o si nyọ̀, o gbà
Ọlọrun gbọ́ pẹlu gbogbo awọn ará ile rẹ̀.
35 Nigbati ilẹ mọ́, awọn olori rán awọn
onṣẹ ọlọpa lati wi pe, Jẹ ki awọn ọkọnrin
wọnni lọ.
36 Onitubu jẹ iṣẹ yi fun Paulu, wipe,
Awọn olori ranṣẹ lati jọwọ nyin lọwọ lọ:
njẹ nisisiyi ẹ jade ki ẹ ma lọ li alafia.
37 Ṣugbọn Paulu dahùn o si wi fun wọn
pe, Nwọn lù wa ni gbangba, nwọn si gbé
wa jù sinu tubu li aijẹbi, awa ẹniti iṣe ara
Romu: nisisiyi nwọn si nfẹ tì wa jade
nikọ̀kọ? bẹ̃kọ; bikoṣepe ki awọn tikara
wọn wá mu wa jade.
38 Awọn ọlọpa si jẹ iṣẹ wọnyi fun awọn
olori: nwọn si bẹ̀ru, nigbati nwọn gbọ́ pe
ara Romu ni nwọn.
39 Nigbati nwọn si de, nwọn ṣipẹ fun
wọn, nwọn si mu wọn jade, nwọn si bẹ̀
wọn pe, ki nwọn ki o jade kuro ninu ilu
na.
40 Nigbati nwọn si jade ninu tubu,
nwọn wọ̀ ile Lidia: nigbati nwọn si ti ri
awọn arakọnrin, nwọn tù wọn ninu, nwọn
si lọ kuro ni ilu na.

## ORI 17.

NIGBATI nwọn si ti kọja Amfipoli ati
Apollonia, nwọn si wá si Tessalonika,
nibiti sinagogu awọn Ju wà:
2 Ati Paulu, bi iṣe rẹ̀ ti ri, o wọle tọ̀
wọn lọ, li ọjọ isimi mẹta, o si mba wọn fi
ọ̀rọ-we-ọ̀rọ ninu iwe-mimọ́,
3 O nṣí i, o si nmu ọ̀rọ jade fun wọn pe,
Kristi kò le ṣaima jìya, ati má jinde kuro
ninu okú; ati pe, Jesu na, ẹniti emi nwasu
fun nyin, on na ni Kristi.
4 Awọn miran ninu wọn gbagbọ́, nwọn
si fi ara mọ́ Paulu on Sila; ati awọn ara
Hellene olufọkansìn ọ̀pọ pipọ, ati awọn
obirin ọlọlá, kì iṣe diẹ.
5 ¶ Ṣugbọn awọn alaigbagbọ́ Ju jowu,
nwọn si fà awọn jagidijagan, ati awọn
ijajẹ enia mọra, nwọn gbá ẹgbẹ jọ, nwọn si
rú gbogbo ilu, nwọn si kọlù ile Jasoni,
nwọn nwá ọ̀na ati mu wọn jade tọ̀ awọn
enia wá.
6 Nigbati nwọn kò si ri wọn, nwọn fà
Jasoni, ati awọn arakọnrin kan pẹlu tọ̀
awọn olori ilu lọ, nwọn nkigbe pe, Awọn
wọnyi ti o nyi aiye po si wá si ihinyi pẹlu;
7 Ẹniti Jasoni gbà si ọdọ: ati gbogbo
awọn wọnyi li o nṣe òdi si ofin Kesari,
wipe, ọba miran kan wà, ẹnikan Jesu.
8 Nwọn si da awọn enia ati awọn olori
ilu nijì, nigbati nwọn gbọ́ nkan wọnyi.

Digitized by Google

9 Nigbati nwọn si gbà onigbọwọ Jasoni ati awọn iyokù, nwọn jọwọ wọn lọwọ lọ.

10 ¶ Ọgan awọn arakọnrin ti rán Paulu on Sila lọ si Berea li oru: nigbati nwọn si de ibẹ̀ nwọn wọ̀ inu sinagogu awọn Ju lọ.

11 Awọn wọnyi si ni iyìn jù awọn ti Tessalonika lọ, niti nwọn fi ọkàn silẹ gbà ọ̀rọ na, nwọn si nwá inu iwe-mimọ́ lojojumọ́ bi nkan wọnyi ri bẽ.

12 Nitorina awọn pipọ ninu wọn si gbagbọ́; ati awọn obirin Hellene ọlọlá, ati ninu awọn ọkọnrin, kì iṣe diẹ.

13 Ṣugbọn nigbati awọn Ju ti Tessalonika gburó pe, Paulu nwasu ọ̀rọ Ọlọrun ni Berea, nwọn si wá sibẹ̀, nwọn si rù ilu.

14 Ọgan awọn arakọnrin si rán Paulu bi ẹnipe ki o lọ si okun: ṣugbọn Sila on Timoteu duro nibẹ̀ na.

15 Awọn olutọju Paulu si mu u wá si Ateni, nigbati nwọn si gbà iṣẹ lọdọ rẹ̀ tọ̀ Sila on Timoteu wá pe, ki nwọn ki o yára tọ̀ on wá, nwọn lọ.

16 ¶ Nigbati Paulu duro dè wọn ni Ateni, ọkàn rẹ̀ rú ninu rẹ̀, nigbati o ri pe gbogbo ilu na kún fun oriṣa.

17 Nitorina o mba awọn Ju fi ọ̀rọ-we-ọ̀rọ ninu sinagogu, ati awọn enia rere, ati li ọjà lojojumọ́ ati pẹlu awọn àyàbá enia.

18 Nigbana li awọn Olumọran (Filosoferi,) kan ninu awọn Ajadun (Epikurei) ati ninu awọn Stoiki, nwọn kó tì i. Awọn kan si nwipe, Kili alahesọ yi yio wi? awọn miran si wipe, O dabi ẹniti yio da ajeji oriṣa silẹ: nitoriti o wasu Jesu, on ajinde fun wọn.

19 Nigbati nwọn si mu u wá sori Areopagu, nwọn wipe, Awa nfẹ mọ̀ kili ẹkọ́ titun ti iwọ nkọ́ni yi jẹ́.

20 Nitoriti iwọ mu ajeji nkan wá si eti wa: awa si nfẹ mọ̀ bi awa iba ti mọ̀ nkan wọnyi si.

21 Nitori gbogbo awọn ará Ateni, ati awọn alejò ti o wà nibẹ̀ kò ṣe ohun miran jù, ki ama rò, tabi ki ama gbọ́ ìhin titun lọ.

22 ¶ Paulu si dide duro larin òkiti Areopagu, o ni, Ẹnyin ọkọnrin Ateni, mo woye pe li ohun gbogbo ẹ kun fun isìnkusìn.

23 Nitori bi emi ti nkọja lọ, ti mo wò ìsin ọlọrun nyin, mo ri pẹpẹ kan ti a kọ akọle yi si, FUN ỌLỌRUN AIMỌ̀. Njẹ ẹniti ẹnyin nsìn li aimọ on na li emi nsọ fun nyin.

24 Ọlọrun ti o da aiye ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀, nitori on na li Oluwa ọrun on aiye, kì igbé ile ti a fi ọwọ́ kọ́;

25 Bẽni a kì ifi ọwọ́ enia sin i, bi ẹnipe o nfẹ nkan, on li o da gbogbo enia li ẽye, ti o si fun wọn li ẹmí ati ohun gbogbo;

26 O si fi ẹ̀jẹ kanna da gbogbo araiye lati tẹ̀do si oju agbaiye, o si ti pinnu akokò ti o yàn tẹlẹ, ati àla itẹdo wọn;

27 Ki nwọn ki o le ma wá Oluwa, bọya bi ọkàn wọn yio le fà si i, ti yio si ri i, bi a tilẹ mọ̀ pe kò jina si olukuluku wa:

28 Nitori lọdọ rẹ̀ li awa gbé wà li ẽye, ti awa nru, ti awa si li ẹmí wa; bi ọkan ninu awọn Poeti ẹnyin tikara nyin ti wi pe, Awa pẹlu si li ọmọ rẹ̀.

29 Njẹ bi awa ba ṣe ọmọ Ọlọrun, kò yẹ fun wa ki a daba pe, Iwa-Ọlọrun dabi wura, tabi fadaka, tabi okuta, ti a fi ọgbọ́n ati ìmọ enia ṣe li ọnà.

30 Pẹlupẹlu igba aimọ̀ yi li Ọlọrun ti mu oju kuro ri; ṣugbọn nisisiyi o paṣẹ fun gbogbo enia nibigbogbo lati ronupiwada:

31 Nitoriti o ti da ọjọ kan, ninu eyi ti yio ṣe idajọ aiye li ododo, nipasẹ ọdọ ọkọnrin na ti o ti yàn; nigbati o ti fi igbẹkẹle fun gbogbo enia, niti o jí i dide kuro ninu okú.

32 ¶ Nigbati nwọn ti gbọ́ ti ajinde okú, awọn miran nṣẹ̀fẹ: ati awọn miran wipe, Awa nfẹ tún nkan wọnyi gbọ́ li ẹnu rẹ.

33 Bẽni Paulu si jade kuro larin wọn.

34 Ṣugbọn awọn ọkọnrin kan fi ara mọ́ ọ, nwọn si gbagbọ́: ninu awọn ẹniti Dionisiu ara Areopagu wà, ati obirin kan ti a npè ni Damari, ati awọn miran pẹlu wọn.

## ORI 18.

LẸHIN nkan wọnyi, Paulu jade kuro ni Ateni, o si lọ si Korinti;

2 O si ri Ju kan ti a npè ni Akuila, ti a bí ni Pontu, ti o ti Itali de nilọlọyi, pẹlu Priskilla aya rẹ̀; (nitori ti Klaudiu paṣẹ pe, ki gbogbo awọn Ju ki o jade kuro ni Romu:) o si tọ̀ wọn wá.

3 Ati itori ti iṣe oniṣẹ ọnà kanna, o si ba wọn joko, o nṣiṣẹ: agọ́ ipa ni iṣẹ ọnà wọn.

4 O si nfi ọ̀rọwerọ fun wọn ninu sinagogu li ọjọjọ isimi, o si nyi awọn Ju ati awọn Hellene li ọkàn pada.

5 Nigbati Sila on Timoteu si ti Makedonia wá, ọkàn Paulu kò gbà fun u, o sọ fun awọn Ju pe, Jesu ni Kristi.

6 Nigbati nwọn si nsọ̀rọ òdi, ti nwọn si nsọ ọ̀rọ buburu, o gbọ̀n aṣọ rẹ̀ nù, o si wi fun wọn pe, Ẹ̀jẹ nyin mbẹ lori ara nyin;

Digitized by Google

ọrùn emi mọ́: lati isisiyi lọ emi o tọ̀ awọn Keferi lọ.

7 ¶ O si lọ kuro nibẹ̀, o wọ̀ ile ọkọnrin kan lọ ti a npè ni Justu, ẹniti o nsìn Ọlọrun, ti ile rẹ̀ fi ara mọ́ sinagogu mọ́timọti.

8 Ati Krispu, olori sinagogu, o gbà Oluwa gbọ́ pẹlu gbogbo awọn ará ile rẹ̀; ati ọ̀pọ ninu awọn ara Korinti, nigbati nwọn gbọ́, nwọn gbagbọ́, a si baptisi wọn.

9 Nigbana li Oluwa sọ fun Paulu li oru li ojuran pe, Máṣe bẹ̀ru, ṣá ma sọ, má si ṣe pa ẹnu rẹ mọ́:

10 Nitoriti emi mbẹ lẹhin rẹ, kò si si ẹniti yio dide si ọ lati pa ọ lara: nitori mo li enia pipọ ni ilu yi.

11 O si joko nibẹ̀ li ọdún kan on oṣù mẹfa, o nkọ́ni li ọ̀rọ Ọlọrun ninu wọn.

12 ¶ Nigbati Gallioni si jẹ bãlẹ Akaia, awọn Ju fi ọkàn kan ṣọ̀tẹ si Paulu, nwọn mu u wá si ile ẹjọ,

13 Nwọn nwipe, Ọkọnrin yi nyi awọn enia li ọkàn pada, lati ma sìn Ọlọrun li ọna ti o lodi si ofin.

14 Nigbati Paulu si nmura ati dahùn, Gallioni wi fun awọn Ju pe, Ibaṣepe ọ̀ran ẹbi, tabi ti jagidijagan kan ni, bi ọ̀rọ ti ri, ẹnyin Ju, emi iba gbè nyin:

15 Ṣugbọn bi o ba ṣe ère ọ̀rọ ati orukọ, ati ti ofin nyin ni, ki ẹnyin ki o fi oju to o; nitoriti emi kì yio ṣe onidajọ irú nkan bawọnni.

16 O si lé wọn kuro ni ile idajọ.

17 Gbogbo awọn ara Hellene si mu Sostene, olori sinagogu, nwọn si lù u niwaju ile ẹjọ. Gallioni kò si ṣú si i ninu nkan wọnni.

18 ¶ Paulu si duro si i nibẹ̀ li ọjọ pipọ, nigbati o si dágbere fun awọn arakọnrin, o ba ti ọkọ̀ lọ si Siria, ati Priskilla ati Akuila pẹlu rẹ̀; o ti fá ori rẹ̀ ni Kenkrea: nitoriti o ti jẹ'jẹ.

19 O si sọkalẹ wá si Efesu, o si fi wọn silẹ nibẹ̀: ṣugbọn on na wọ̀ inu sinagogu lọ, o si ba awọn Ju fi ọ̀rọwerọ.

20 Nigbati nwọn si bẹ̀ ẹ pe, ki o ba awọn joko diẹ si i, o kọ̀;

21 Ṣugbọn o dágbere fun wọn, wipe, Emi kò gbọdọ ṣaima ṣe ọdún ajọ ti mbọ̀ yi ni Jerusalemu bi o ti wù ki o ri: ṣugbọn emi o si tún pada tọ̀ nyin wá, bi Ọlọrun ba fẹ. O si ṣikọ̀ ni Efesu.

22 Nigbati o si ti gúnlẹ ni Kesarea, ti o goke, ti o si ki ijọ, o sọkalẹ lọ si Antioku.

23 Nigbati o si gbé ọjọ diẹ nibẹ̀, o lọ, o si kọja ni ilẹ Galatia on Frigia lẹsẹsẹ, o nmu gbogbo awọn ọmọ-ẹhin li ọkàn le.

24 ¶ Ju kan si wà ti a npè ni Apollo, ti a bí ni Aleksandria, ọkọnrin ọlọrọ li ẹnu, ti o pọ̀ ni iwe-mimọ́, o wá si Efesu.

25 Ọkọnrin yi li a ti kọ́ ni ipa ti Oluwa; o si ṣe ẹniti o gboná li ọkàn, o nfi aiṣemẹlẹ sọ̀rọ, o si nkọ́ni ni nkan ti Oluwa, kìki baptismu ti Johannu li o mọ̀.

26 O si bẹ̀rẹ si isọ li aibẹ̀ru ni sinagogu: nigbati Akuila on Priskilla ti gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀, ẹniti nwọn mu si ọdọ, nwọn si sọdi ọ̀na Ọlọrun fun u li asọtan.

27 Nigbati ọkàn rẹ̀ si fà lati kọja lọ si Akaia, awọn arakọnrin kọwe, nwọn bẹ̀ awọn ọmọ-ẹhin ki nwọn ki o gbà a: nigbati o si de, ẹniti o ràn awọn ti o gbagbọ́ nipa ore-ọfẹ lọwọ:

28 Nitoriti o sọ asọye fun awọn Ju ni gbangba, o nfi i hàn ninu iwe-mimọ́ pe, Jesu ni Kristi.

## ORI 19.

O SI ṣe, bi Apollo ti wà ni Korinti, ti Paulu kọja lọ niha ẹkùn oke, o wá si Efesu: nigbati o si ri awọn ọmọ-ẹhin kan,

2 O bi wọn pe, Ẹnyin gbà Ẹmí Mimọ́ na nigbati ẹnyin ti gbagbọ́? Nwọn si wi fun u pe, Awa kò gbọ́ rara bi Ẹmí Mimọ́ kan wà.

3 O si bi wọn pe, Njẹ baptismu wo li a ha baptisi nyin si? Nwọn si wipe, Si baptismu ti Johannu.

4 Paulu si wipe, Nitõtọ ni Johannu fi baptismu ti ironupiwada baptisi, o nwi fun awọn enia pe, ki nwọn ki o gbà ẹniti mbọ̀ lẹhin on gbọ́, eyini ni Kristi Jesu.

5 Nigbati nwọn si gbọ́, a baptisi wọn li orukọ Jesu Oluwa.

6 Nigbati Paulu si fi ọwọ́ le wọn, Ẹmí Mimọ́ si bà le wọn; nwọn si nfọ̀ ède miran, nwọn si nsọ asọtẹlẹ.

7 Iye awọn ọkọnrin na gbogbo to mejila.

8 Nigbati o si wọ̀ inu sinagogu lọ, o sọ̀rọ li aibẹ̀ru li oṣù mẹta, o nfi ọ̀rọwerọ, o si nyi wọn ni iyè pada si nkan ti iṣe ti ijọba Ọlọrun.

9 Ṣugbọn nigbati awọn miran ninu wọn di lile, ti nwọn kò si gbagbọ́, ti nwọn nsọ̀rọ ibi si ipa-ọ̀na na niwaju ijọ enia, o lọ kuro lọdọ wọn, o si yà awọn ọmọ-ẹhin sọ̀tọ, o si nsọ asọye li ojojumọ́ ni ile iwe ẹnikan ti a npè ni Tirannu.

10 Eyiyi nlọ niwọn ọdún meji; bẹ̃i

Digitized by Google

gbogbo awọn ti o wà ni Asia gbọ́ ọ̀rọ Jesu Oluwa, ati awọn Ju ati awọn Hellene.
11 Ọlọrun si ti ọwọ́ Paulu ṣe iṣẹ aṣẹ akanṣe:
12 Tobẽ ti a fi nmu gèle, ati ibantẹ́ ara rẹ̀ tọ̀ awon olokunrun lọ, arùn si fi wọn silẹ, ati awọn ẹmi buburu si jade kuro lara wọn.
13 ¶ Ṣugbọn awọn Ju kan alarinkiri, alẹmi-ẹ̀su-jade dawọle e li adabọwọ ara wọn, lati pè orukọ Jesu Oluwa si awọn ti o li ẹmi buburu, wipe, Awa fi orukọ Jesu ti Paulu nwasu fi nyin bú.
14 Awọn kan meje si wà, ọmọ ẹnikan ti a npè ni Skefa, Ju, ati olori kan ninu awọn alufa, ti nwọn ṣe bẽ.
15 Ẹmi buburu na si dahùn, o ni, Jesu emi mọ̀, Paulu emi si mọ̀; ṣugbọn tali ẹnyin?
16 Nigbati ọkọnrin ti ẹmi buburu wà lara rẹ̀ si fò mọ́ wọn, o damu wọn, o bori wọn, bẽni nwọn sá jade kuro ni ile na, ni ìhoho ati ni ifarapa.
17 Ihìn yi si di mimọ̀ fun gbogbo awọn Ju ati awọn ara Hellene pẹlu ti o ṣe atipo ni Efesu; ẹ̀ru si ba gbogbo wọn, a si gbé orukọ Jesu Oluwa ga.
18 Ọ̀pọ awọn ti nwọn si gbagbọ́ wá, nwọn si jẹwọ, nwọn si fi iṣẹ wọn hàn.
19 Nigbati awọn pipọ pẹlu ti iṣe iṣẹkiṣẹ kò iwe wọn jọ, nwọn dáná sun wọn loju gbogbo awọn enia: nwọn si ṣìro iye wọn, nwọn si ri i, o jẹ ẹgbãmẹdọgbọ̀n ìwọn fadaka.
20 Bẽli ọ̀rọ Oluwa si wú si i gidigidi o si gbilẹ.
21 ¶ Bi nkan wọnyi ti pari tan, Paulu pinnu rẹ̀ li ọkàn pe, nigbati on ba kọja ni Makedonia ati Akaia, lati lọ si Jerusalemu, o wipe, Lẹhin igba ti mo ba de ibẹ̀, emi kò le ṣaima ri Romu pẹlu.
22 Bẽli o rán awọn meji ninu awọn iranṣẹ rẹ̀ si Makedonia, Timoteu ati Erastu; ṣugbọn on tikararẹ̀ duro ni Asia ni igba diẹ na.
23 Li akokò na irú diẹ ki o wà nitori ọ̀na na.
24 Nitori ọkọnrin kan ti a npè ni Demetriu, alagbẹdẹ fadaka, ti ima ṣe ile oriṣa fadaka fun Diana, ti o mu èrè ti kò mọ̀ ni ìwọn fun awọn oniṣọnà wa;
25 Nigbati o pè wọn jọ, ati irú awọn ọlọnà bẽ, o ni, Alàgba, ẹnyin mọ̀ pe nipa ọnà yi li awa fi li ọrọ̀ wa.
26 Ẹnyin si ri, ẹnyin si gbọ́ pe, kì iṣe ni Efesu nikanṣoṣo ni, ṣugbọn o fẹrẹ ṣe gbogbo Asia, ni Paulu yi ti nkọ́ ti o si nyi ọ̀pọ enia li ọkàn pada, wipe, Ohun ti a fi ọwọ́ ṣe, kì iṣe ọlọrun:
27 Kò si ṣe pe kìki iṣẹ ọnà wa yi li o wà li ewu lati sọ dasan; ṣugbọn ile Diana oriṣa nla, yio si di gigàn, ati gbogbo ọlanla rẹ̀ yio si run, ẹniti gbogbo Asia ati gbogbo aiye mbọ.
28 Nigbati nwọn gbọ́ ọ̀rọ wọnyi, inu wọn kún fun ibinu, nwọn kigbe, wipe, Oriṣa-nla ni Diana ti ara Efesu.
29 Gbogbo ilu na si kún fun irukerudò: nwọn fi ọkàn kan rọ́ sinu ile ibiṣire, nwọn si mu Gaiu ati Aristarku ara Makedonia, awọn ẹgbẹ ájọrin Paulu.
30 Nigbati Paulu si nfẹ wọ̀ inu awujọ awọn enia lọ, awọn ọmọ-ẹhin kò jẹ fun u.
31 Awọn olori kan ara Asia, ti iṣe ọrẹ́ rẹ̀ ranṣẹ si i, nwọn bẹ̀ ẹ pe, ki o máṣe fi ara rẹ̀ wewu ninu ile ibiṣire.
32 Njẹ ọkan nwi eyi, ekeji nwi eyini: nitori ajọ di rudurudu; ati ọ̀pọ enia ni kò mọ̀ itori ohun ti nwọn tilẹ fi wọjọ pọ̀ si.
33 Nwọn si fà Aleksanderu kuro li awujọ, awọn Ju tì i ṣaju. Aleksanderu si juwọ́ ṣe apejure si wọn, on iba si wi ti ẹnu rẹ̀ fun awọn enia.
34 Ṣugbọn nigbati nwọn mọ̀ pe Ju ni, gbogbo wọn li ohùn kan, niwọn wakati meji ọjọ, kigbe pe, Oriṣa nla ni Diana ti ara Efesu.
35 Nigbati akọwe ilu si tù ijọ enia ninu, o ni, Ẹnyin ọkọnrin Efesu, ọkọnrin wo li o wà ti kò mọ̀ pe, ilu ara Efesu ni iṣe olusin ti Diana oriṣa nla, ati ti ere ti o ti ọdọ Seusi (Jupiteri) bọ́ silẹ?
36 Njẹ ki a kiyesi i pe, nkan wọnni kò ni isọrọ òdi si, o yẹ ki ẹ dakẹ, ki ẹnyin ki o máṣe fi iwara ṣe ohunkohun.
37 Nitoriti ẹnyin mu awọn ọkọnrin wọnyi wá, bẽni nwọn kò kó ile ọlọrun, bẽni nwọn kò ṣe ẹniti o sọ̀rọ buburu si ọlọrun nyin.
38 Njẹ nitorina bi Demetriu, ati awọn oniṣọnà ti o wà pẹlu rẹ̀, ba li ọ̀rọ kan si ẹnikẹni, ofin ṣí silẹ, awọn onidajọ si wà: jẹ ki nwọn ki o lọ ifi ara wọn sùn.
39 Bi o si ṣe pe ẹnyin mbère ohun miran, a o pinnu rẹ̀ ni ijọ ti o yẹ si i.
40 Awa sá wà li ewu ati pè bi lẽrè nitori ariwo oni yi, kò si idi ohun ti awa le fi rojọ iwọjọ yi.
41 Nigbati o si ti sọ bẽ tan, o tú ijọ na ká.

Digitized by Google

## ORI 20.

LẸHIN igbati ariwo na rọlẹ, Paulu pè
awọn ọmọ-ẹhin, o si gbà wọn ni iyan-
ju, o dagbere fun wọn, o dide lati lọ si
Makedonia.
2 Nigbati o si rè ìha apa wọnni, ti o si
sọ̀rọ iyanju pipọ fun wọn, o wá si ilẹ
Hellene,
3 O si duro nibẹ̀ li oṣù mẹta. Nigbati
awọn Ju si dèna dè e, bi o ti npete ati ba
ti ọkọ̀ lọ si Siria, o pinnu rẹ̀ lati ba ti
Makedonia pada lọ.
4 Sopateru ara Berea si ba a lọ de Asia;
ati ninu awọn ara Tessalonika, Aristarku
on Sekundu; ati Gaiu ara Derbe, ati
Timoteu; ati ara Asia, Tikiku on Trofimu.
5 Awọn wọnyi nlọ niwaju, nwọn duro
dè wa ni Troa.
6 Awa si ṣikọ̀ lati Fillippi wá lẹhin ọjọ
aiwukara, awa si de ọdọ wọn ni ijọ karun;
nibiti awa gbé duro ni ijọ meje.
7 Li ọjọ isimi ikini nigbati awọn ọmọ-
ẹhin pejọ lati bù akara, Paulu si wasu fun
wọn, o mura ati lọ ni ijọ keji; o si fà ọ̀rọ
rẹ̀ gùn titi di arin ọganjọ.
8 Fitilà pipọ si wà ni yàrá oke na,
nibiti a gbé pejọ si.
9 Ọdọmọkọnrin kan ti a npè ni Eutiku
joko li oju ferese, nigbati orun si wọ̀ ọ
lara: bi Paulu si ti pẹ ni iwasu, o tagbọn-
gbọ́n loju orun, o ṣubu lati oke kẹta wá
silẹ, a si gbé e dide li okú.
10 Nigbati Paulu si sọkalẹ, o wolẹ bò o,
o gbá a mọra, o ni, Ẹ má yọ ara nyin lẹnu;
nitori ẹmí rẹ̀ mbẹ lara rẹ̀.
11 Nigbati o si tún gòke lọ, ti o si bù
akara, ti o jẹ, ti o si sọ̀rọ pẹ titi o fi di
afẹmọjumọ́, bẹ̃li o lọ.
12 Nwọn si mu ọmọkọnrin na bọ̀ lãye,
kì isi iṣe diẹ ni inu wọn tutù.
13 ¶ Nigbati awa si ṣaju, awa si ṣikọ̀ lọ
si Asso, nibẹ̀ li awa nfẹ gbà Paulu si ọkọ̀:
nitori bẹ̃li o ti pinnu rẹ̀, on tikararẹ̀ nfẹ
ba ti ẹsẹ lọ.
14 Nigbati o pade wa ni Asso, awa si
gbà a si ọkọ̀, awa lọ si Mitilene.
15 Nigbati awa si ṣikọ̀ nibẹ̀, ni ijọ keji
awa de ọkankan Kio; ni ijọ keji rẹ̀ awa de
Samo, awa si duro ni Trogillioni; ni ijọ
keji rẹ̀ awa si de Miletu.
16 Paulu sá ti pinnu rẹ̀ lati mu ọkọ̀ lọ
niha Efesu, nitori kò yẹ fun u lati fi igbana
joko ni Asia: o si nyára bi yio le kò fun
u, ki o wà ni Jerusalemu li ọjọ Pentikọsti.
17 ¶ Lati Miletu o ranṣẹ si Efesu, lati
pè awọn alàgba ijọ wá sọdọ rẹ̀.
18 Nigbati nwọn si de ọdọ rẹ̀, o wi fun
wọn pe, Ẹnyin mọ̀, lati ọjọ ti mo ti kọ́ de
Asia, bi emi ti ba nyin gbé nigbagbogbo,
19 Bi emi ti nfi ìrẹlẹ ọkàn sìn Oluwa,
ati pẹlu omije pipọ, ati idanwò, ti o bá mi,
nipa ìdena awọn Ju:
20 Bi emi kò si ti pa nkan mọ́ ti o ṣe
egbè fun nyin, emi fi hàn nyin, emi si kọ́
nyin ni gbangba ati lati ile de ile,
21 Emi nsọ fun awọn Ju, ati fun awọn
Hellene pẹlu, ironupiwada sipa Ọlọrun, ati
igbagbọ́ sipa Jesu Kristi Oluwa wa.
22 Njẹ nisisiyi, ẹ kiyesi i, ọkàn mi nfà
si ati lọ si Jerusalemu, emi kò mọ̀ ohun ti
yio bá mi nibẹ̀:
23 Bikoṣe bi Ẹmí Mimọ́ ti nsọ ni ilu
gbogbo pe, ìde on ìya mbẹ niwaju mi.
24 Ṣugbọn ọkan ninu nkan wọnyi kò
kọ mi li omnú, bẹ̃li emi kò si kà ẹmí mi
ṣọwọn fun ara mi, ki emi ki o le fi ayọ̀ là
ipa mi já, ati iṣẹ iranṣẹ ti mo ti gbà lọdọ
Jesu Oluwa, lati ma rò ihin-rere ore-ọfẹ
Ọlọrun.
25 Njẹ nisisiyi, kiyesi i, emi mọ̀ pe
gbogbo nyin, ninu ẹniti emi ti nkiri wasu
ijọba Ọlọrun, kì yio ri oju mi mọ́.
26 Njẹ emi pè nyin ṣe ẹlẹri loni pe,
ọrùn mi mọ́ kuro lọwọ ẹ̀jẹ enia gbogbo.
27 Nitoriti emi kò fasẹhin lati sọ gbogbo
ìmọ Ọlọrun fun nyin.
28 ¶ Nitorina ẹ kiyesara nyin, ati si
gbogbo agbo ti Ẹmí Mimọ́ fi nyin ṣe ala-
bojuto, lati ma bọ́ ijọ enia Ọlọrun, ti o fi
ẹ̀jẹ ara rẹ̀ rà.
29 Nitoriti emi mọ̀ eyi pe, lẹhin lilọ mi,
ikõkò buburu yio wọ̀ inu nyin, li aikù agbo
silẹ.
30 Ati ninu ara ẹnyin tikara nyin li
awọn ọkọnrin yio dide, ti nwọn o ma sọ̀rọ
ohun òdi, lati fà awọn ọmọ-ẹhin sẹhin wọn.
31 Nitorina ẹ ma ṣọra, ki ẹ si ranti pe,
niwọn ọdún mẹta, emi kò dẹkun lati fi
omije kilọ fun olukuluku li ọsán ati li oru.
32 Njẹ nisisiyi, ará, emi fi nyin le Ọlọ-
run lọwọ, ati ọ̀rọ ore-ọfẹ rẹ̀, ti o le mu
nyin duro, ati ti o le fun nyin ni ilẹ-nini
ninu awọn ti a wẹnumọ́.
33 Emi kò ṣe ojukòkoro fadaka, tabi
wura, tabi aṣọ ẹnikẹni.
34 Ẹnyin tikara nyin sá mọ̀ pe, ọwọ́
wọnyi li o ṣiṣẹ ohun ti emi ṣe alaini, ati
fun awọn ti o wà lọdọ mi pẹlu.
35 Emi fi nkan gbogbo hàn nyin pe,
nipa ṣiṣe bẹ̃, ẹnyin iba ma ràn awọn alai-

Digitized by Google

lera lọwọ, ki ẹ si ma ranti ọ̀rọ Jesu Oluwa,
bi o ti wi pe, Ati funni ni ibukún jù ati
gbà lọ.
36 ¶ Nigbati o si wi nkan wọnyi, o
kunlẹ o si ba gbogbo wọn gbadura.
37 Gbogbo wọn si sọkun gidigidi, nwọn
si rọ̀ mọ́ ọ li ọrùn, nwọn si fi ẹnu kò o li
ẹnu,
38 Ãnu ṣe wọn jù gbogbo rẹ̀ lọ fun ọ̀rọ
ti o sọ pe, nwọn kì yio ri oju on mọ́.
Nwọn si sìn i lọ sinu ọkọ.

## ORI 21.

O SI ṣe, nigbati awa yà ara wa kuro lọdọ
wọn, awa ṣikọ̀, awa ba ọ̀na tàra wá si
Koosi, o si di ijọ keji awa de Rodu, ati lati
ibẹ̀ lọ si Patara:
2 Nigbati awa si ri ọkọ̀ kan ti nrekọja
lọ si Fenike, awa wọ̀ ọkọ̀, awa si ṣí.
3 Nigbati awa si ti ri Kipru li òkere, ti
awa fi i si ọwọ́ òsi, awa gbé ori ọkọ̀ le Siria,
awa si gúnlẹ ni Tire: nitori ibẹ̀ li ọkọ̀ yio
gbé kó ẹrù silẹ.
4 Nigbati awa si ri awọn ọmọ-ẹhin, awa
duro nibẹ̀ ni ijọ meje: awọn ẹniti o fi Ẹmí
wi fun Paulu pe, ki o máṣe gòke lọ si
Jerusalemu.
5 Nigbati ọjọ wọnni pé tan, awa jade,
awa si mu ọ̀na wa pọ̀n; gbogbo wọn si sìn
wa, pẹlu awọn obirin ati awọn ọmọde titi
awa fi jade si ẹhin ilu: nigbati awa si
kunlẹ li ẹbadò, awa si gbadura.
6 Nigbati awa si ti dágbere fun ara wa,
awa bọ́ si ọkọ̀; awọn si pada lọ si ile wọn.
7 Nigbati awa si tọ̀ ipa wa já lati Tire
wá, awa de Ptolemai, nigbati awa si kí
awọn arakọnrin, awa ba wọn gbé ni ijọ
kan.
8 Ni ijọ keji awa ti o wà ni ẹgbẹ ti
Paulu lọ, awa de Kesarea: nigbati awa si
wọ̀ ile Filippi Efangelisti, ọkan ninu awọn
meje nì; awa si wọ̀ sọdọ rẹ̀.
9 Ọkọnrin na si li ọmọbirin mẹrin,
wundia, ti ima sọtẹlẹ.
10 Bi awa ti wà nibẹ̀ li ọjọ pipọ, woli
kan ti Judea sọkalẹ wá, ti a npè ni Agabu.
11 Nigbati o si de ọdọ wa, o mu amure
Paulu, o si dì ara rẹ̀ li ọwọ́ on ẹsẹ, o si
wipe, Bayi li Ẹmí Mimọ́ wi, Bayi li awọn
Ju ti o wà ni Jerusalemu yio dì ẹniti o li
amure yi, nwọn o si fi i le awọn Keferi
lọwọ.
12 Bi awa si ti gbọ́ nkan wọnyi, ati
awa, ati awọn ará ibẹ̀ na bẹ̀ ẹ pe, ki o
máṣe gòke lọ si Jerusalemu.
13 Paulu si dahùn wipe, Ewo li ẹnyin
nṣe yi, ti ẹnyin nsọkun, ti ẹnyin si mbà
mi ninu jẹ; nitori emi kò mura kìki ati
dè nikan, ṣugbọn ati kú pẹlu ni Jerusalemu,
nitori orukọ Jesu Oluwa.
14 Nigbati a kò le pa a li ọkàn dà, awa
dakẹ, wipe, Ifẹ ti Oluwa ni ki a ṣe.
15 Lẹhin ijọ wọnni, awa kó ẹrù wa, awa
si gòke lọ si Jerusalemu.
16 Awọn kan ninu awọn ọmọ-ẹhin ara
Kesarea ba wa lọ, nwọn si mu Mnasoni
àgba ọmọ-ẹhin kan pẹlu wọn, ara Kipru,
lọdọ ẹniti awa o gbé wọ̀.
17 Nigbati awa si de Jerusalemu, awọn
arakọnrin si fi ayọ̀ gbà wa si ọdọ.
18 Ni ijọ keji awa ba Paulu lọ sọdọ
Jakọbu; awọn alàgba gbogbo si wà nibẹ̀.
19 Nigbati o si kí wọn tan, o si ròhin
ohun gbogbo lẹsẹsẹ, ti Ọlọrun ṣe ninu
awọn Keferi nipa iṣẹ iranṣẹ rẹ̀.
20 Nigbati nwọn si gbọ́, nwọn yìn
Oluwa logo, nwọn si wi fun u pe, Iwọ ri i,
arakọnrin, iye ẹgbẹrun melo awọn Ju ti o
gbagbọ́; gbogbo wọn ni kò fi ofin jafara:
21 Nwọn si ti rò fun wọn nitori rẹ pe,
Iwọ nkọ́ gbogbo awọn Ju ti o wà ninu
awọn Keferi pe, ki nwọn ki o kọ̀ Mose silẹ,
ati pe ki nwọn ki o máṣe kọ ọmọ wọn ni
ilà mọ́, ati ki nwọn ki o máṣe rìn nipa
iṣe na.
22 Njẹ kini? ijọ kò le ṣaima pejọ pọ̀:
nwọn o sá gbọ́ pe, iwọ de.
23 Njẹ eyi ti awa o wi fun ọ yi ni ki o
ṣe: Awa li ọkọnrin mẹrin ti nwọn ni ẹ̀jẹ́
lara;
24 Awọn ni ki iwọ ki o mu, ki o si wẹ̀
ara rẹ pẹlu wọn, ki o si ba wọn ṣe inawo
pọ̀, ki nwọn ki o le fá ori wọn: ki gbogbo
enia ki o le mọ̀ pe, ohun ti a sọ fun wọn
nitori rẹ asan ni; ati pe, iwọ tikararẹ nrìn
dede, iwọ si npa ofin mọ́.
25 Bi o ṣe ti awọn Keferi ti o gbagbọ́ ni,
awa ti kọwe, awa si ti pinnu rẹ̀ pe, ki nwọn
ki o máṣe kiyesi irú nkan wọnni, ṣugbọn
ki nwọn ki o fà sẹhin kuro ninu ohun ti a
pa bọ oriṣa, ati ẹ̀jẹ, ati ohun ilọlọrùn-pa,
ati àgbere.
26 Nigbana ni Paulu mu awọn ọkọnrin
na, ni ijọ keji o si wẹ̀ ara rẹ̀ pẹlu wọn, o
wọ̀ inu tempili lọ, lati ṣe apẹrẹ atipé ọjọ
iwẹnumọ́, titi a o fi rubọ fun olukuluku
wọn.
27 Bi ijọ keje si ti fẹrẹ pé, nigbati awọn
Ju ara Asia ri i ni tempili, nwọn rú gbo-
gbo awọn enia soke, nwọn nawọ́ mu u.
28 Nwọn nkigbe wipe, Ọkọnrin Israeli,
ẹ gbà wa: Eyiyi li ọkọnrin, ti nkọ́ gbogbo

Digitized by Google

enia nibi gbogbo li òdi si awọn enia, ati si
ofin, ati si ihinyi: ati pẹlu o si mu awọn
ara Hellene wá si tempili, o si mba ibi
mimọ́ yi jẹ.
29 (Nitoriti nwọn ti ri Trofimu ará
Efesu pẹlu rẹ̀ ni ilu, ẹniti nwọn ṣebi Paulu
mu wọ̀ inu tempili lọ.)
30 Gbogbo awọn ara ilu si dide, awọn
enia si sure jọ: nwọn si mu Paulu, nwọn
wọ́ ọ jade kuro ninu tempili: lojukanna
ilẹkun si ti sé.
31 Bi nwọn si ti nwá ọ̀na ati pa a, ìhin
de ọdọ olori ẹgbẹ ogun pe, ariwo gbà gbo-
gbo Jerusalemu.
32 Ẹniti o si ti mu ọmọ-ogun ati ba-
logun ọrún lọgan, o si sure sọkalẹ tọ̀ wọn
lọ: nigbati nwọn si ri olori ogun ati awọn
ọmọ-ogun, nwọn fi Paulu silẹ ilù.
33 Nigbana li olori ogun sunmọ ọ, o si
gbà a lọwọ wọn, o ni, ki nwọn ki o fi ẹ̀wọn
meji dè e; o si bère ẹniti iṣe, ati ohun ti
o ṣe.
34 Bi ọkan si nwi eyi, ekeji ama wi
miran ninu ajọ: nigbati kò si le mọ̀ otitọ
idi irukerudò na, o ni, ki nwọn ki o mu u
lọ sinu ilu-odi.
35 Nigbati o si de ori àkasọ, gbigbé li a
gbé e soke lọwọ awọn ọmọ-ogun nitori
agbara awọn enia.
36 Nitori ọ̀pọ enia gbatì i, nwọn nkigbe
pe, Ẹ mu u kuro.
37 Bi nwọn si ti fẹrẹ imu Paulu wọ̀ inu
ilu-odi lọ, o bi olori ogun pe, Emi gbọdọ
ba ọ sọ̀rọ? Ẹniti o si dahùn wipe, Iwọ mọ̀
ède Hellene ifọ̀?
38 Iwọ ki iṣe ara Egipti nì, ṣaju ọjọ
wọnyi ti o ṣọ̀tẹ, ti o si mu ẹgbaji ọkọnrin
lẹhin lọ si ijù ti nwọn ṣe apania?
39 Paulu si wipe, ọkọnrin Ju li emi, ara
Tarsu ilu ni Kilikia, ọlọ̀tọ ilu ti kì iṣe
talàkà ilu: emi bẹ̀ ọ jẹ ki emi ba awọn
enia na sọrọ.
40 Nigbati o si jẹ fun u, Paulu duro lori
àkasọ, o si juwọ́ si awọn enia. Nigbati
nwọn si dakẹ-rọrọ, o sọ̀rọ fun wọn li ède
Heberu, wipe,

## ORI 22.

ALAGBA, ará, ati baba, ẹ gbọ ti ẹnu mi
nisisiyi.
2 (Nigbati nwọn si gbọ́ pe o nfọ̀ ède
Heberu si wọn, nwọn si dakẹrọrọ si i: o si
wipe,)
3 Ọkọnrin Ju nitõtọ li emi, ẹniti a bí
ni Tarsu ilu kan ni Kilikia, ṣugbọn ti a tọ́
ni ilu yi, li ẹsẹ Gamalieli, ti a kọ́ li akọtan
nipa ofin nwọn baba, ti nkò si fi ìsin nipa
ti Ọlọrun jafara, gẹgẹ bi ẹnyin ti ri li oni.
4 Mo si ṣe inunibini si ọ̀na yi titi o fi di
pipa, emi ndè, emi si nfi wọn sinu tubu,
ati ọkọnrin ati obirin.
5 Gẹgẹ bi olori alufa yio ti gbà mi li
ẹrí jẹ, ati gbogbo ajọ awọn alàgba: lọdọ
awọn ẹniti mo gbà iwe lọ si Damasku si
awọn arakọnrin, lati mu awọn ti o wà nibẹ̀
ni didè wá si Jerusalemu, lati jẹ wọn niyà.
6 O si ṣe, pe, bi emi ti nlọ, ti emi si
sunmọ eti Damasku niwọn ọsángangan, li
ojijì, imọlẹ nla mọ́ ti ọrun wá yi mi ká.
7 Mo si ṣubu lùlẹ, emi si ngbọ́ ohùn ti
npè mi pe, Saulu, Saulu, ẽṣe ti iwọ fi nṣe
inunibini si mi?
8 Emi si dahùn wipe, Iwọ tani, Oluwa?
O si dahùn wipe, Emi Jesu ti Nasareti, ti
iwọ nṣe inunibini si ni.
9 Awọn ti o si wà pẹlu mi ri imọlẹ na
nitõtọ, ẹ̀ru si ba wọn; ṣugbọn nwọn kò
gbọ́ ohùn ẹniti nfọ̀ si mi.
10 Emi si wipe, Kili emi o ha ṣe, Oluwa?
Oluwa si wi fun mi pe, Dide, ki o lọ si
Damasku; nibẹ̀ li a o gbé sọ ohun gbogbo
fun ọ ti a yàn silẹ fun ọ lati ṣe.
11 Bi emi kò si ti le riran nitori mimọ́
imọlẹ na, nigbati a si ti ọwọ́ awọn ti o wà
lọdọ mi fà mi lọ, mo wọ̀ Damasku.
12 Ati ẹnikan Anania, ọkọnrin olufọ-
kansìn nipa ofin, ti o ni ihin rere lọdọ
gbogbo awọn atipo Ju ti o wà nibẹ̀.
13 Tọ̀ mi wá, o si duro tì mi, o wi fun
mi pe, Saulu arakọnrin, riran. Ni wakati
kanna mo si ṣiju soke wò o.
14 O si wipe, Ọlọrun awọn baba wa yàn
ọ, lati mọ̀ ifẹ tirẹ̀, ati lati ri Ẹni Olõtọ nì,
ati ki iwọ ki o si gbọ́ ohùn li ẹnu rẹ̀.
15 Ki iwọ ki o le ṣe ẹlẹri rẹ̀ fun gbogbo
enia, ninu ohun ti iwọ ri ti iwọ si gbọ́.
16 Kini iwọ si duro si nisisiyi? dide, ki
a baptisi rẹ, ki o si wẹ̀ ẹ̀ṣẹ rẹ nù, ki o si
ma pè orukọ Oluwa.
17 O si ṣe pe, nigbati mo pada wá si
Jerusalemu, ti emi ngbadura ni tempili mo
wà li ojuran;
18 Mo si ri i o wi fun mi pe, Yara, ki o
jade kuro ni Jerusalemu kánkán: nitoriti
nwọn kì yio gbà ẹrí rẹ sipa mi.
19 Emi si wipe, Oluwa, nwọn mọ̀ pe,
emi ama sọ sinu tubu, emi a si ma lù awọn
ti o gbà orukọ rẹ gbọ́ ninu sinagogu gbo-
gbo:
20 Nigbati a ta ẹ̀jẹ Stefanu ẹlẹri rẹ silẹ,
emi pẹlu duro nibẹ̀, mo si li ohùn si ikú
rẹ̀, mo si nṣe itọju aṣọ awọn ẹniti o pa a.

Digitized by Google

21 O si wi fun mi pe, Lọ: nitori emi o
rán ọ lọ si òkere rére si awọn Keferi.
22 Nwọn si fi etí silẹ fun u de ọ̀rọ yi,
nwọn si gbé ohùn wọn soke wipe, Ẹ mu
irú eyiyi kuro li aiye: nitori kò yẹ ki o
wà lãye.
23 Bi nwọn si ti nke, ti nwọn bọ aṣọ
wọn silẹ, ti nwọn nku ekuru si oju ọrun,
24 Olori ogun paṣẹ pe ki a mu u wá
sinu ilu odi, o ni ki a fi ìna bi i lẽre; ki o
le mọ̀ itori ohun ti nwọn ṣe nkigbe si i bẹ̃.
25 Bi nwọn si ti fi ọṣán dì i, Paulu bi
balogun ọrún ti o duro tì i pe, O tọ́ fun
nyin lati nà ẹniti iṣe ará Romu li aijẹbi?
26 Nigbati balogun ọrún si gbọ́, o lọ, o
wi fun olori ogun pe, Kiyesara li ohun ti
iwọ nṣe yi: nitori ara Romu li ọkọnrin yi
iṣe.
27 Nigbana li olori ogun de, o si bi i pe,
Sọ fun mi, ara Romu ni iwọ iṣe? O si
dahùn wipe, Bẹ̃ni.
28 Olori ogun si dahùn wipe, Owo iye-
biye ni mo fi gbà ọlá omnira yi. Paulu si
wipe, Ibilẹ li emi.
29 Lojukanna awọn ti iba fi ìna bi i lẽre
kuro lọdọ rẹ̀: olori ogun si bẹ̀ru, nigbati o
mọ̀ pe ara Romu ni, ati itori ti o dè e.
30 Ni ijọ keji, nigbati o nfẹ mọ̀ itori
ohun ti awọn Ju ṣe fi i sùn, o tú u kuro
lori ìde, o ni, ki awọn olori alufa ati gbo-
gbo ajọ igbimọ ki o wá, nigbati o si mu
Paulu sọkalẹ, o mu u duro niwaju wọn.

## ORI 23.

NIGBATI Paulu si tẹjumọ ajọ igbimọ, o
ni, Alàgba, ará, emi ti mbẹ ni ìwa
inu rere gbogbo niwaju Ọlọrun titi o fi di
oni yi.
2 Anania olori alufa si wi fun awọn ti o
duro leti ọdọ rẹ̀, ki nwọn ki o gbún u li ẹnu.
3 Nigbana ni Paulu wi fun u pe, Ọlọrun
yio lù ọ, iwọ ogiri funfun: iwọ joko lati
wadi ọ̀ran mi nipa ofin, iwọ si pe ki a lù
mi li òdi si ofin?
4 Awọn ti o si duro leti ọdọ rẹ̀ ni, Iwọ
ngàn olori alufa Ọlọrun?
5 Paulu si dahùn pe, Arakọnrin, emi kò
mọ̀ pe olori alufa ni: nitoriti a kọwe rẹ̀ pe,
Iwọ kò gbọdọ sọ̀rọ buburu si olori awọn
enia rẹ.
6 Nigbati Paulu si kiyesi i pe, apakan
wọn jẹ Sadusi, ati apakan jẹ Farisi, o ke ni
ajọ igbimọ pe, Alàgba, ará, Farisi li emi,
ọmọ Farisi: nitori ireti ati ajinde okú li a
ṣe pè mi bi lẽre.
7 Nigbati o si ti wi eyi, iyapa de fun ẹ̀ya
awọn Farisi, ati ti awọn Sadusi: ajọ si pin
meji si ara wọn.
8 Nitoriti awọn Sadusi wipe, kò si
ajinde, kò si angeli, tabi ẹmí: ṣugbọn
awọn Farisi jẹwọ mejeji.
9 O si di ariwo nla: awọn akọwe ti o
wà li apa ti awọn Farisi dide, nwọn njà,
wipe, Awa kò ri ohun buburu kan lara
ọkọnrin yi: bi o ba ṣepe ẹmí tabi angeli
kan li o ba a sọ̀rọ, ẹ máṣe jẹ ki awa ba
Ọlọrun jà.
10 Nigbati iyapa si di nla, ti olori ogun
bẹ̀ru ki Paulu ki o má bà di fifaya lọwọ
wọn, o rán awọn ọmọ-ogun sọkalẹ lọ lati
fi agbara já Paulu lọwọ wọn, ki nwọn si
mu u wá sinu ilu odi.
11 Li oru ijọ na Oluwa duro tì i, o ni,
Paulu, Daraya: nitori bi iwọ ti jẹri mi ni
Jerusalemu, bẹ̃ni iwọ o si jẹrí ni Romu
pẹlu.
12 Nigbati ilẹ mọ́, awọn Ju kan mulẹ,
nwọn fi ara wọn bura pe, awọn kì yio jẹ,
bẹ̃li awọn kì yio mu, titi awọn o fi pa
Paulu.
13 Awọn ti o mulẹ yi si jù ọ̀ji enia lọ.
14 Nigbati nwọn si tọ̀ olori alufa ati
awọn alàgba lọ, nwọn ni, Awa fi ẹ̀pe nla
dè ara wa pe, awa kì yio tọ́ nkan wò titi
awa o fi pa Paulu.
15 Njẹ nisisiyi ki ẹnyin pẹlu ajọ igbimọ
wi fun olori ogun, ki o mu Paulu sọkalẹ tọ̀
nyin wá li ọla, bi ẹnipe ẹnyin nfẹ nkan
bère dajudaju nitori rẹ̀: ki o to sunmọ
itosi, awa o si ti mura lati pa a.
16 Nigbati ọmọ arabirin Paulu si gburó
ìdena wọn, o lọ o si wọ̀ inu ilu odi lọ, o si
sọ fun Paulu.
17 Nigbana ni Paulu pè ọkan ninu awọn
balogun ọrún sọdọ rẹ̀, o ni, Mu ọmọdekọn-
rin yi tọ̀ olori ogun lọ: nitoriti o ni nkan
ti yio sọ fun u.
18 Nigbati o si mu u, o sìn i lọ sọdọ
olori ogun, o ni, Paulu ondè, o pè mi sọdọ
rẹ̀, o si bẹ̀ mi pe ki ẹmi mu ọmọdekọnrin
yi tọ̀ ọ wá, ẹniti o ni nkan ti yio sọ fun ọ.
19 Nigbana li olori ogun fà a lọwọ, o si
mu u rè apakan fun ara rẹ̀, o si bère pe,
Kini iwọ ni isọ fun mi?
20 O si wipe, Awọn Ju fi ìmọ ṣọkan lati
wá ibẹ̀ ọ ki o le mu Paulu sọkalẹ wá si ajọ
igbimọ li ọla, bi ẹnipe nwọn nfẹ bère nkan
si i dajudaju lọwọ rẹ̀.
21 Ṣugbọn ki o máṣe gbọ́ ti wọn: nito-
riti awọn ti o dèna dè e ninu wọn jù ogoji
ọkọnrin lọ, ti nwọn bura pe, awọn kì yio
jẹ, bẹ̃li awọn kì yio mu, titi awọn o fi pa

Digitized by Google

a: ati nisisiyi nwọn ti mura tan, nwọn nreti idahùn lọdọ rẹ.
22 Nigbana li olori ogun jọwọ ọmọdekọnrin na lọwọ lọ, o si kìlọ fun u pe, Máṣe wi fun ẹnikan pe, iwọ fi nkan wọnyi hàn mi.
23 Nigbati o si pè awọn balogun ọrún meji sọdọ rẹ̀, o ni, Ẹ mura igba ọmọ-ogun silẹ, lati lọ si Kesarea, ati adọrin ẹlẹṣin, ati igba ọlọkọ̀, ni wakati kẹta oru;
24 Ẹ si pèse ẹranko, ti nwọn o gbé Paulu gùn, ki ẹnyin ki o le mu u lọ li alafia sọdọ Feliksi bãlẹ.
25 O si kọ iwe bayi pe:
26 Klaudiu Lisia si Feliksi bãlẹ ọlọlájulọ, alafia.
27 Awọn Ju mu ọkọnrin yi, nwọn si npete lati pa a: nigbana ni mo de pẹlu ogun, mo si gbà a lọwọ wọn nigbati mo gbọ́ pe ara Romu ni.
28 Nigbati emi si nfẹ mọ̀ idi ọ̀ran ti nwọn fi i sùn si, mo mu u sọkalẹ si ajọ igbimọ wọn:
29 Ẹniti mo wa mọ̀ pe, nwọn fisùn nitori ọ̀ran ofin wọn, bẽni nwọn kò kà nkan ti o tọ́ si ikú ati si ìde si i lọrùn.
30 Nigbati a si ti sọ fun mi bi awọn Ju ti dèna dè ọkọnrin na, ọgan mo si rán a si ọ, mo si paṣẹ fun awọn olufisùn rẹ̀ pẹlu, lati wi niwaju rẹ ohun ti nwọn ni isọ si i. Alafia.
31 Nigbana li awọn ọmọ-ogun, gẹgẹ bi a ti rán wọn, nwọn gbà Paulu, nwọn si mu u li oru lọ si Antipatri.
32 O di ijọ keji nwọn jọwọ awọn ẹlẹṣin lati ma ba a lọ, awọn si pada wá sinu odi:
33 Nigbati awọn si de Kesarea, ẹniti o fi iwe fun bãlẹ, nwọn si mu Paulu wá si iwaju rẹ̀.
34 Nigbati bãlẹ si ti kà iwe na, o bère pe ara igberiko wo ni iṣe. Nigbati o si gbọ́ pe ara Kilikia ni;
35 O ni, Emi o gbọ́ ẹjọ rẹ, nigbati awọn olufisùn rẹ ba de pẹlu. O si wi pe ki nwọn ki o pa a mọ́ ni gbàngan idajọ Herodu.

## ORI 24.

LẸHIN ijọ marun Anania olori alufa sọkalẹ lọ pẹlu awọn alàgba, ati ẹnikan Tertulu alagbasọ, ẹniti o fi Paulu sùn bãlẹ.
2 Nigbati a si ti pè e jade, Tertulu bẹ̀rẹ si ifi i sùn pe, Alafia pipọ li awa njẹ nipasẹ rẹ, ati iṣẹ ogo ti o nti ọwọ́ rẹ ṣe fun orilẹ yi nipa imoye rẹ.
3 Ati nigbagbogbo, ati ni ibi gbogbo, li awa nfi ọpẹ́ tẹwọgbà a, Feliksi ọlọlà-julọ.
4 Ṣugbọn ki emi ki o máṣe fà a gùn lọ titi fun ọ, mo bẹ̀ ọ ki o le fi lãkari rẹ gbọ́ ọ̀rọ diẹ li ẹnu wa.
5 Nitori awa ri ọkọnrin yi, o jẹ alaṣeràn enia, ọlọ̀tẹ ninu gbogbo awon Ju ti o wà ni gbogbo aiye, ati olori ẹ̀ya awọn Nasarene:
6 Ẹniti o si nlọ ibà tempili jẹ: ti awa si mu, ti awa iba ba-wijọ bi ofin wa.
7 Ṣugbọn Lisia olori ogun de, o fi agbara nla gbà a li ọwọ́ wa,
8 O si rán awọn olufisùn rẹ̀ wá sọdọ rẹ: ni iwadi ẹjọ rẹ̀, iwọ tikararẹ yio woye gbogbo nkan wọnyi, nitori ohun ti awa ṣe fi i sùn.
9 Awọn Ju pẹlu si fi ohùn ṣọkan, wipe, bẽni nkan wọnyi ri.
10 Nigbati bãlẹ ṣapẹrẹ si i pe ki o sọ̀rọ, Paulu si dahùn wipe, Bi mo ti mọ̀ pe iwọ ti ṣe onidajọ fun orilẹ-ède yi lati ọdún meloyi wá, mo fi ayọ̀ pipọ jù dahùn fun ara mi:
11 Nitori ki o le yé ọ pe, ijejila pére yi ni mo gòke lọ si Jerusalemu lati lọ isìn.
12 Bẽni nwọn kò ri mi ni tempili ki emi ki o ma ba ẹnikẹni jà, bẽli emi kò ṣe irukerudò ninu awọn enia, tabi ninu sinagogu, tabi ni ilu:
13 Bẽni nwọn kò le ladi ohun ti nwọn fi mi sùn si nisisiyi.
14 Ṣugbọn eyiyi ni mo jẹwọ fun ọ, pe bi ipa ti a npè ni adamọ̀, bẽli emi nsìn Ọlọrun awọn baba mi, emi ngbà nkan gbogbo gbọ́ ti a kọ sinu ofin, ati sinu iwe awọn woli:
15 Mo si ni ireti sipa ti Ọlọrun, ti awọn tikara wọn jẹwọ pẹlu, pe ajinde okú mbọ̀, ati ti olõtọ, ati ti alaiṣõtọ.
16 Ninu eyi li emi si nṣe idaraya, lati li ọkàn ti kò li ẹ̀ṣẹ sipa ti Ọlọrun, ati si enia nigbagbogbo.
17 Ṣugbọn lẹhin ọdún pipọ, emi mu ọrẹ ãnu fun orilẹ-ède mi wá, ati ọrẹ Ọlọrun.
18 Ninu eyiyi li awọn Ju kan lati Asia wá ri mi ni iwẹnu ni tempili, bẽni kì iṣe ti emi ti awujọ, tabi ti emi ti irukerudò.
19 Awọn ti o yẹ ti nwọn iba wà nihinyi niwaju rẹ, ki nwọn ki o já mi ni koro, bi nwọn ba li ohunkohun si mi.
20 Bi kò ṣe bẽ, jẹ ki awọn ti o wà nihinyi ki o wi, bi nwọn ba ri iṣe buburu kan lọwọ mi, bi mo ti duro niwaju ajọ igbimọ yi,
21 Bikoṣe ti gbolohùn kan yi, ti mo ke nigbati mo duro li awujọ wọn, Nitori ajinde okú li a ṣe pè mi bi lẽre lọdọ rẹ loni yi.
22 Nigbati Feliksi gbọ́ nkan wọnyi, oye

Digitized by Google

sa ye e li ayetan ni ipa-ọna na ; o tú wọn
ká na, o ni, Nigbati Lisia olori ogun ba
sọkalẹ wá, emi o mọ̀ idi ọ̀ran nyin jalẹ.
23 O si wi fun balogun ọrún kan pe, ki
o mã ṣe itọju Paulu, ki o si bùn u làye, ati
pe ki o máṣe dá awọn ojulumọ̀ rẹ̀ lẹkun,
lati mã ṣe iranṣẹ fun u, ati lati mã tọ̀ ọ wá.
24 Ṣugbọn lẹhin ijọ melokan, Feliksi de
pẹlu Drusilla obirin rẹ̀, ti iṣe ọmọbirin Ju,
o ranṣẹ pè Paulu, o si gbọ́ ọ̀rọ lọdọ rẹ̀ nipa
igbagbọ́ ti Kristi.
25 Bi o si ti nsọ asọye nipa ti ododo,
airekọja, ati idajọ ti mbọ̀, ẹ̀ru ba Feliksi, o
dahùn wipe, Mã lọ nisisiyi na ; nigbati mo
ba si ni akokò ti o wọ̀, emi o ranṣẹ pè ọ.
26 O reti pẹlu pe a ba fun on li owo lati
ọwọ́ Paulu wá, ki on ki o le da silẹ : nito-
rina a si ma ranṣẹ si i nigbakugba, ama ba
a sọ̀rọ.
27 Ṣugbọn lẹhin ọdún meji, Porkiu
Festu rọpò Feliksi : Feliksi si nfẹ ṣe oju're
fun awọn Ju, o fi Paulu silẹ li ondè.

## ORI 25.

NJẸ nigbati Festu de igberiko na, lẹhin
ijọ mẹta o gòke lati Kesarea lọ si
Jerusalemu.
2 Nigbana li olori alufa ati awọn alàgba
ninu awọn Ju fi Paulu sùn u, nwọn si bẹ̀ ẹ,
3 Nwọn nfẹ ore lọdọ rẹ̀ si Paulu, ki o le
ranṣẹ si i wá si Jerusalemu : nwọn ndèna
dè e lati pa a.
4 Ṣugbọn Festu wipe, ki a pa Paulu mọ́
ni Kesarea, ati pe on tikara on o pada lọ ni
lọ̃lọ̃yi.
5 O ni, njẹ awọn ti o le lọ ninu nyin, ki
nwọn ki o ba mi sọkalẹ lọ, bi ìwa buburu
kan ba wà lara ọkọnrin yi, ki nwọn ki o fi
i sùn.
6 Nigbati o duro lọdọ wọn le ni ijọ
mẹwa, o sọkalẹ lọ si Kesarea ; o si di ijọ
keji o joko lori itẹ́ idajọ, o ranṣẹ pè Paulu
jade wá.
7 Nigbati o si de, awọn Ju ti o ti Jeru-
salemu sọkalẹ wá duro yi i ká, nwọn nkà
ọ̀ran pipọ ti o buru si Paulu lọrùn, ti nwọn
kò le ladi.
8 Nigbati o dahùn fun ara rẹ̀, o ni, Kì
iṣe si ofin awọn Ju, bẽni kì iṣe si tempili,
bẽni kì si iṣe si Kesari li emi ṣẹ̀ ẹ̀ṣẹkẹṣẹ
rara.
9 Ṣugbọn Festu nfẹ ṣe oju-rere fun awọn
Ju, o da Paulu lohùn, wipe, Iwọ nfẹ goke
lọ si Jerusalemu, lati wadi nkan wọnyi ni-
bẹ̀ niwaju mi bi ?
10 Paulu si dahùn wipe, Emi duro ni-
waju itẹ́ idajọ Kesari, nibiti a ba gbé wadi
ẹjọ mi : emi kò ṣe ohun kan ẹ̀ṣẹ si awọn
Ju, bi iwọ tikararẹ ti mọ̀ daju.
11 Bi o ba si ṣepe mo ṣe ọlẹṣẹ, tabi bi
mo ba si ṣe ohun kan ti o yẹ si ikú, emi kò
kọ̀ lati kú : ṣugbọn bi kò ba si nkan wọnni
ninu ohun ti awọn wọnyi fi mi sùn si, ẹni-
kan kò le fi mi fun wọn. Mo fi ọ̀ran mi lọ
Kesari.
12 Nigbana ni Festu lẹhin ti o ba ajọ
gbìmọ, o da Paulu lohùn pe, Iwọ fi ọ̀ran rẹ
lọ Kesari ? Lọdọ Kesari ni iwọ o lọ.
13 Ṣugbọn lẹhin ijọ melokan, Agrippa
ọba, ati Bernike sọkalẹ wá si Kesarea lati
kí Festu.
14 Bi nwọn ti wà nibẹ̀ li ọjọ pipọ, Festu
sọ ọ̀ran Paulu fun ọba, wipe, A fi ọkọnrin
kan silẹ li ondè lati ọwọ́ Feliksi wá :
15 Nigbati mo wà ni Jerusalemu, nitori
ẹniti awọn olori alufa ati awọn alàgba
awọn Ju sọ fun mi, nwọn nfẹ idajọ si i.
16 Awọn ẹniti mo si da lohùn pe, Kì iṣe
iṣe awọn ara Romu lati da ẹnikẹni lẹbi
ikú, ki ẹniti a fisùn ki o to kò olufisùn rẹ̀
loju, ki o si ri àye dahùn fun ara rẹ̀, nitori
ọ̀ran ti a kà si i lọrùn,
17 Njẹ nigbati nwọn si jùmọ wá si ihin-
yi, ọgan mo ti joko lori itẹ́ idajọ ni ijọ
keji, mo ranṣẹ pè ọkọnrin na wá.
18 Nigbati awọn olufisùn na si dide,
ẹniti nwọn kò si fisùn si irú ọ̀ran ti mo
tanma :
19 Bikoṣe nitori ọ̀ran isìn wọn kan ti
nwọn mba a jiyàn, ati ti ẹnikan Jesu, ti o
ti kú, ti Paulu tẹnumọ́ pe o wà lãye.
20 Nitori ti oju mi kò da si irú ọ̀rọ bẽ,
mo bi i pe, bi o nfẹ lọ si Jerusalemu, ki a
si wadi ọ̀ran wọnyi nibẹ̀.
21 Ṣugbọn nigbati Paulu wipe ki a pa
on mọ́ dè igbọ́ ẹjọ Augustu, mo si ti fun
wọn li ohùn lati pa a mọ́ titi emi o fi le rán
a lọ sọdọ Kesari.
22 Agrippa si da Festu lohùn, o ni, Emi
nfẹ gbọrọ ọkọnrin na tikara mi. O si
wipe, Lọla iwọ o gbọrọ rẹ̀.
23 Nigbati o di ijọ keji, ti Agrippa on
Bernike wá, ti awọn ti ọṣọ́ pipọ, ti nwọn
si wọle ibi igbẹjọ, pẹlu awọn olori ogun,
ati awọn alàgba ilu, Festu ranṣẹ, nwọn mu
Paulu jade.
24 Festu si dahùn wipe, Agrippa ọba,
ati gbogbo enia ti o ba wa pejọ, ẹnyin ri
ọkọnrin yi, nitori ẹniti gbogbo ajọ awọn Ju
ti rọgbaká mi si, ati ni Jerusalemu, ati ni-
hinyi, ti nwọn nkigbe pe, Kò yẹ fun u lati
gbé aiyé mọ́.

Digitized by Google

25 Ṣugbọn emi kò ri pe, o ṣe nkan ti o
yẹ si ikú, ati bi on tikara rẹ̀ si ti fi ọ̀ran rẹ̀
lọ Augustu, mo ti pinnu rẹ̀ lati rán a lọ.
26 Nipa ẹniti emi kò ri nkan dede ti
emi iba kọwe si oluwa mi. Nitorina ni
mo ṣe mu u jade tọ̀ nyin wá, ati pẹlupẹlu
niwaju rẹ, Agrippa ọba, lẹhin igbati ẹnyin
ba tọsẹ rẹ̀, ki emi ki o le ri ohun kan
kọwe.
27 Nitori ti kò wọ̀ li oju mi lati rán
ondè, ki a má si sọ idi ọ̀ran ti a kà si i
lọrùn.

## ORI 26.

AGRIPPA si wi fun Paulu pe, A fun ọ
làye lati sọ ti ẹnu rẹ. Nigbana ni
Paulu nawọ́, o si sọ ti ẹnu ara rẹ̀ pe:
2 Agrippa ọba, inu emi tikarami dùn
nitoriti emi o dahùn fun ara mi loni niwa-
ju rẹ, nitori nkan gbogbo ti a nfi mi sùn
lati ọdọ awọn Ju.
3 Pẹlupẹlu ti emi mọ̀ pe, gbogbo iṣe ati
iyàn awọn Ju ni iwọ mọ̀ daju: nitorina
emi bẹ̀ ọ ki iwọ ki o fi sũru gbọrọ mi.
4 Iwà mi lati igba ewe, lati ibẹrẹ wa ni
Jerusalemu, lãrin awọn ará ilu mi, gbogbo
awọn Ju mọ̀.
5 Awọn ti o mọ̀ mi lati ipilẹṣẹ, bi o ba
ṣepe nwọn jẹ jẹri pe, bi ipa-ọna aidẹra isìn
iyapa wa Farisi li emi.
6 Ati nisisiyi nitori ireti ileri ti a ti ṣe
fun awọn baba lati ọdọ Ọlọrun wá ni mo
duro ni ìpe li ẹjọ yi:
7 Si ohun ti ẹ̀ya orilẹ wa mejila, li aisi-
mi ati li ọsán ati li oru nsìn Ọlọrun, ti
nwọn nreti ati-de. Nitori ireti na li a fi
mi sùn lati ọdọ awọn Ju wá, Agrippa ọba.
8 Ẽṣe ti a o fi rò o si ohun ti kò ṣe gba-
gbọ́ fun ọ pe, Ọlọrun o jí okú dide?
9 Emi tilẹ rò ninu ara mi nitõtọ pe,
emi ni iba ṣe ohun òdi pipọ si orukọ Jesu
ti Nasareti.
10 Ohun ti mo si ṣe ni Jerusalemu:
awọn pipọ ninu awọn enia mimọ́ ni mo há
mọ́ inu tubu, nigbati mo ti gbà aṣẹ lọdọ
awọn olori alufa; nigbati nwọn si npa
wọn, mo li ohùn si i.
11 Nigbakugba ninu sinagogu gbogbo
mo ṣẹ́ wọn niṣẹ, mo fi agbara ṣe ki nwọn
ki o sọ̀rọ buburu; nigbati mo ṣoro si wọn
gidigidi, mo ṣe inunibini si wọn de àjeji
ilu.
12 Ninu rẹ̀ na bi mo ti nlọ si Damasku
ti emi ti ọlá ati aṣẹ ikọ̀ lati ọdọ awọn
olori alufa lọ,
13 Ọba, mo ri li ọ̀na li ọsángangan,
imọlẹ lati ọrun wá, o jù rirán õrùn lọ, o
mọlẹ yi mi ká, ati awọn ti o mba mi rè
àjo.
14 Nigbati gbogbo wa si ṣubu lulẹ mo
gbọ́ ohùn ti nfọ̀ si mi, li ède Heberu pe,
Saulu, Saulu, ẽṣe ti iwọ fi nṣe inunibini si
mi? O ṣoro fun ọ lati tapá si ẹgún.
15 Emi si bère pe, Iwọ tani Oluwa? O
si dahùn pe, Emi ni Jesu ti iwọ nṣe inuni-
bini si.
16 Ṣugbọn dide, ki o si fi ẹsẹ rẹ tẹlẹ:
nitorina ni mo ṣe fi ara hàn fun ọ lati yàn
ọ li onṣẹ ati ẹlẹri, ati ti ohun ti iwọ ti ri,
ati ti ohun ti emi o fi ara hàn fun ọ;
17 Emi o ma gbà ọ lọwọ awọn enia, ati
lọwọ awọn Keferi, ẹniti emi rán ọ si nisi-
siyi,
18 Lati ṣí wọn li oju, lati yi wọn pada
kuro ninu òkunkun si imọlẹ, ati lọwọ
agbara Satani si Ọlọrun, ki nwọn ki o le ri
idariji ẹ̀ṣẹ gbà, ati ọrọ̀ ilẹ-nini pẹlu awọn ti
a sọdi mimọ́ nipa igbagbọ ninu mi.
19 Bẽ na, Agrippa ọba, emi kò si ṣe
aigbọran si iran ọrun na.
20 Ṣugbọn mo tète sọ fun awọn ará
Damasku, ati ni Jerusalemu, ati já gbogbo
ẹkùn Judea, ati fun awọn Keferi, ki nwọn
ki o ronupiwada, ki nwọn ki o si yipada si
Ọlọrun, ki nwọn ki o si ṣe iṣẹ ti o yẹ si
ironupiwada.
21 Nitori nkan wọnyi li awọn Ju mu mi
ni tempili, ti nwọn si nlọ lati pa mi.
22 Bi mo si ti nri ìtilẹhin gbà lọdọ
Ọlọrun, mo duro titi o fi di oni, emi njẹri
fun ewe ati fun àgba, emi kò wi ohun
miran bikoṣe ohun ti awọn woli ati Mose
ti wi pe yio ṣẹ:
23 Pe, Kristi yio jìya, ati pe on ni
yio kọ́ jinde kuro ninu okú, ki o le fi
imọlẹ hàn fun awọn enia ati fun awọn
Keferi.
24 Bi o si ti nsọ t'ẹnu rẹ̀, Festu dahùn
o wi li ohùn rara pe, Paulu, ori rẹ bajẹ;
ẹkọ́ akọjù ba ọ li ori jẹ.
25 O si dahùn pe, Ori mi kò bajẹ, Festu
ọlọlájulọ; ṣugbọn ọ̀rọ otitọ ati ti airekọja
li emi nsọ jade.
26 Nitori ti ọba mọ̀ ohun gbogbo wọnyi,
niwaju ẹniti emi nsọ̀rọ li aibẹ̀ru: nitori
ọkàn mi sọ fun mi pe, kò si nkan ti o lumọ̀
fun u ninu nkan wọnyi; nitoriti a kò ṣe
kini yi ni ìkọkọ.
27 Agrippa ọba, iwọ gbà awọn woli gbọ́?
Emi mọ̀ pe, iwọ gbagbọ́.
28 Agrippa si wi fun Paulu pe, Iwọ fẹrẹ
yi mi li ọkàn pada lati di Kristiani.

Digitized by Google

29 Paulu si wipe, Emi bẹ̀ Ọlọrun, ki o má ṣe iwọ nikanṣoṣo li o fẹrẹ, ṣugbọn ki gbogbo awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ mi loni pẹlu ki o fẹrẹ, ati ki nwọn si dà bi emi ti dà, bikoṣe li aini ìde wọnyi.

30 Nigbati o si sọ nkan wọnyi tan, ọba dide, ati bãlẹ, ati Bernike, ati awọn ti o ba wọn joko:

31 Nigbati nwọn lọ si apakan, nwọn ba ara wọn sọ̀rọ pe, Ọkọnrin yi kò ṣe nkankan ti o yẹ si ikú tabi si ìde.

32 Agrippa si wi fun Festu pe, A ba jọwọ ọkọnrin yi lọwọ, bioṣepe kò ti fi ọ̀ran rẹ̀ lọ̀ Kesari.

## ORI 27.

BI nwọn si ti pinnu rẹ̀ lati ṣikọ̀ lọ si Itali, nwọn fi Paulu, ati awọn ondè miran kan pẹlu le balogun ọrún kan lọwọ, ti a npè ni Juliu, li ẹgbẹ ogun Augustu.

2 Nigbati awa si wọ̀ ọkọ̀ Adramittiu kan, ti o mura lati lọ si ìha Asia, awa ṣikọ̀; Aristarku, ara Makedonia ti Tessalonika, o wà pẹlu wa.

3 Ni ijọ keji awa de Sidoni. Juliu si ṣe inu rere si Paulu, o si bùn u làye ki o mã tọ̀ awọn ọrẹ́ rẹ̀ lọ lati tù ara rẹ̀ lara.

4 Nigbati awa si ṣikọ̀ nibẹ̀, awa lọ labẹ Kipru, nitori ti afẹfẹ ṣọwọ ọ̀di.

5 Nigbati awa rekọja okun Kilikia on Pamfilia, awa de Mira ilu Likia.

6 Nibẹ̀ ni balogun ọrún si ri ọkọ̀ Aleksandria kan, ti nlọ si Itali; o si fi wa sinu rẹ̀.

7 Nigbati awa nlọ jẹ́jẹ li ọjọ pipọ, ti awa fẹrẹ má de ọkankan Knidu, ti afẹfẹ kò bùn wa làye, awa lọ labẹ Krete, li ọkankan Salmone;

8 Nigbati awa si fẹrẹ má kọja rẹ̀, awa de ibi ti a npè ni Ebute yiyànju; ti o sunmọ ibiti ilu Lasea ti wà ri.

9 Nigbati awa si sọ ọjọ pipọ nù, ti ati ta igbokun wa idi ewu tan, nitori àwẹ ti kọja, Paulu da imọran kan fun wọn,

10 O si wi fun wọn pe, Alàgba, mo woye pe iṣikọ̀ yi yio li ewu ati òfo pipọ, kì iṣe kìki ti ẹrù ati ti ọkọ̀, ṣugbọn ti ẹmí wa pẹlu.

11 Ṣugbọn balogun ọrún gbà ti olori ọkọ̀ ati ti ọlọkọ̀ gbọ́, jù ohun ti Paulu wi lọ.

12 Nitori ebute na kò si rọrùn lati potutù nibẹ̀, awọn pipọ si damọran pe, ki a lọ kuro nibẹ̀, bi nwọn o le làkàka de Fenike lati potutù; ibi ebute Krete ti o kọjusi ìha òsi ìwọ õrùn, ati ọtún ìwọ õrùn.

13 Nigbati afẹfẹ gusù si fẹ jẹ́jẹ, ti nwọn ṣebi ọwọ awọn tẹ̀ ohun ti nwọn nwá, nwọn pa ori ọkọ̀ dà, nwọn npá ẹba Krete lọ.

14 Kò si pẹ lẹhin rẹ̀ ti ìji ti a npè ni Euroklidoni fẹ lù u.

15 Nigbati o si ti gbé ọkọ̀, ti kò si le dojukọ ìji na, awa jọwọ rẹ̀, o ngbá.

16 Nigbati o si gbá lọ labẹ erekuṣu kan ti a npè ni Klauda, o di iṣẹ pipọ ki awa ki o to le sunmọ ọpẹrẹ:

17 Nigbati nwọn si gbé e soke, nwọn nṣe iranlọwọ, nwọn ndì ọkọ̀ ni isalẹ̀; nigbati nwọn si bẹru ki nwọn ki o máṣe bọ sinu iyanrìn-didẹ̀, awa tagbokun, bẹ̃li awa ngbá kiri.

18 Awa si mbì kiri gidigidi ninu ìji na, ni ijọ keji nwọn kó nkan dà si omi lati mu ọkọ̀ fẹrẹ;

19 Ati ni ijọ kẹta, awa fi ọwọ́ ara wa kó èlo ọkọ̀ sọnù.

20 Nigbati õrùn ati irawọ kò hàn li ọjọ pipọ, ti ìji kò si mọ̀ niwọn fun wa, abá atilà kò si fun wa mọ́.

21 Lẹhin aijẹun ọjọ pipọ, Paulu dide larin wọn, o ni, Alàgba, ẹnyin iba ti gbà ti emi gbọ́, ki a máṣe lọ kuro ni Krete, ewu yi kì ba ti wú wa, ati òfo yi kì ba ti ṣe nyin.

22 Njẹ nisisiyi mo gbà nyin niyanju, ki ẹ tújuka: nitori kì yio si òfo ẹmí ẹnikan ninu nyin, bikoṣe ti ọkọ̀.

23 Nitoriti angeli Ọlọrun, ti ẹniti emi iṣe, ati ẹniti emi nsìn, o duro tì mi li oru aná,

24 O wi fun mi pe, Má bẹru, Paulu; a kò le ṣaima mu ọ de iwaju Kesari: si wo o, Ọlọrun fi gbogbo awọn ti o ba ọ wọkọ̀ pọ̀ fun ọ.

25 Njẹ nitorina, alàgba, ẹ daraya: nitori mo gbà Ọlọrun gbọ́ pe, yio ri gẹgẹ bi a ti sọ fun mi.

26 Ṣugbọn awa o gbá lù erekuṣu kan.

27 Bi o si ti di oru ijọ kẹrinla, ti awa ngbá sihin gbá sọhún ni Adria, larin ọganjọ awọn atukọ̀ tanmã pe, awọn sunmọ eti ilẹ kan;

28 Nigbati nwọn si wọ̀n okun, nwọn ri i o jinlẹ li ogún ìwọn ẹsẹ mẹfa: nigbati nwọn si sún siwaju diẹ, nwọn si tún wọ̀n okun, nwọn ri i o jinlẹ ni mẹ̃dogun ìwọn ẹsẹ mẹfa.

29 Nigbati nwọn bẹru ki nwọn ki o

Digitized by Google

máṣe gbá lù ibi okuta, nwọn sọ idakọró mẹrin silẹ ni idi ọkọ̀, nwọn nreti ojumọ́.

30 Bi awọn atukọ̀ si ti nwá ọ̀na ati sá kuro ninu ọkọ̀, nigbati nwọn sọ ọpẹrẹ si oju omi bi ẹnipe nwọn npete ati sọ idakọró silẹ niwaju ọkọ̀,

31 Paulu wi fun balogun ọrún ati fun awọn ọmọ-ogun pe, Bikoṣepe awọn wọnyi ba duro ninu ọkọ̀ ẹnyin kì yio le là.

32 Nigbana li awọn ọmọ-ogun ke okùn ọpẹrẹ, nwọn jọwọ rẹ̀ o ṣubu sọhún.

33 Nigbati ilẹ nmọ́ ibọ̀, Paulu bẹ̀ gbogbo wọn ki nwọn ki o jẹun diẹ, o wipe, Oni li o di ijẹrinla ti ẹnyin ti nreti, ti ẹnyin ti wà li aijẹun, ti ẹ kò fi ète ba nkan.

34 Nitorina mo bẹ̀ nyin, ki ẹ jẹun diẹ: nitori eyi ni fun ilera nyin: nitori irun kan kì yio ré kuro li ori ẹnikan nyin.

35 Nigbati o si wi nkan wọnyi, ti o si mu akara, o si dupẹ lọwọ Ọlọrun niwaju gbogbo wọn: nigbati o si bù u, o bẹrẹ si ijẹ.

36 Nigbana ni gbogbo wọn si daraya, awọn pẹlu si gbà onjẹ.

37 Gbogbo awọn ti o wà li ọkọ̀ na si jẹ ọrinlugba ọkàn o dí mẹrin.

38 Nigbati nwọn jẹun yó tan, nwọn kó nkan danù kuro ninu ọkọ̀, nwọn si kó alikama dà si omi.

39 Nigbati ilẹ mọ, nwọn kò mọ̀ ilẹ na: ṣugbọn nwọn ri apa odò kan ti o li ebute, nibẹ̀ ni nwọn nrò, bi o ba le ṣe, ki nwọn ki o tì ọkọ̀ si.

40 Nigbati nwọn si fà idakọró wọnni soke, nwọn kọri si agbami, nigbati nwọn si tú ìde itọkọ̀, ti nwọn si ta igbokun nla si afẹfẹ, nwọn wá ikọjusi ilẹ.

41 Nigbati nwọn si bọ si ibi ti okun meji pade, nwọn fi ọkọ̀ sọlẹ; iwaju rẹ̀ si kàn mọlẹ ṣinṣin, o wà kò le yi, ṣugbọn agbara riru omi fọ́ idi ọkọ̀ na.

42 Ìro awọn ọmọ-ogun ni ki a pa awọn ondé, ki ẹnikẹni wọn ki o má ba wẹ̀ jade sá lọ.

43 Ṣugbọn balogun ọrún nfẹ gbà Paulu là, o kọ̀ ìro wọn; o si wi fun awọn ti o le wẹ̀ ki nwọn ki o tète bọ si okun lọ si ilẹ:

44 Ati awọn iyokù, omiran lori apako, ati omiran lori ẹfọkọ̀. Bẽli o si ṣe ti gbogbo wọn yọ li alafia de ilẹ.

## ORI 28.

NIGBATI gbogbo wọn si yọ tan ni nwọn wa mọ̀ pe, Melita li a npè erekuṣu na.

2 Kì si iṣe ore diẹ li awọn alaigbede na ṣe fun wa: nitoriti nwọn daná, nwọn si gbà gbogbo wa si ọdọ, nitori òjo igba na, ati itori otutù.

3 Nigbati Paulu si ṣà ìdi iwọ́n-wọn igi jọ, ti o si fi i le iná, pamọlẹ kan ti inu oru jade, o dì mọ́ ọ li ọwọ́.

4 Bi awọn alaigbede na ti ri ẹranko olọró na ti dì mọ́ ọ li ọwọ́, nwọn ba ara wọn sọ pe, Dajudaju apania li ọkọnrin yi, ẹniti o yọ ninu okun tan, ṣugbọn ti ẹsan kò jẹ ki o wà lãye.

5 On si gbọ̀n ẹranko na sinu iná, ohunkohun kan kò ṣe e.

6 Ṣugbọn nwọn nwoye igbati yio wú, ti yio si ṣubu lulẹ kú lojukanna: nigbati nwọn wò titi, ti nwọn kò si ri nkan ki o ṣe e, nwọn pa iyè da pe, ọlọrun kan li ọkọnrin yi.

7 Li àgbegbe ibẹ̀ ni ilẹ ọkọnrin kan ọlọlá erekuṣu na wà, orukọ ẹniti a npè ni Publiu; ẹniti o gbà wa si ọdọ, ti o si fi inu rere mu wa wọ̀ ni ijọ mẹta.

8 O si ṣe, baba Publiu dubulẹ arùn ibà ati ọ̀rin: ẹniti Paulu wọle tọ̀, ti o si gbadura fun, nigbati o si fi ọwọ́ le e, o si mu u larada.

9 Nigbati eyi si ṣe tan, awọn ẹlomiran iyokù, ti o li arùn li erekuṣu na, nwọn tọ̀ ọ wá, o si mu wọn larada:

10 Awọn ẹniti nwọn bù ọlá pipọ fun wa: nigbati awa si nlọ, nwọn dì nkan gbogbo rù wa ti a ba ṣe alaini.

11 Lẹhin oṣù mẹta awa wọ̀ ọkọ̀ Aleksandria kan, ti o potutù li erekuṣu na, àmi eyi ti iṣe Kastoru on Poluksu.

12 Nigbati awa gúnlẹ ni Sirakuse, awa gbé ibẹ̀ ni ijọ mẹta.

13 Lati ibẹ̀ nigbati awa yiká, awa de Regioni: ni ijọ keji afẹfẹ gusù fẹ, o si di ijọ keji rẹ̀ awa si de Puteoli:

14 Nibiti awa gbé ri awọn arakọnrin, ti nwọn si bẹ̀ wa lati ba wọn gbé ni ijọ meje: bẽli awa si lọ si ìha Romu.

15 Nigbati awọn arakọnrin gburó wa, lati ibẹ̀ nwọn wá titi nwọn fi de Apii Foroni, ati Arojẹ mẹta, lati pade wá: ẹni, nigbati Paulu ri, o dupẹ lọwọ Ọlọrun, o mu ọkàn le.

16 Nigbati awa si de Romu, balogun ọrún fi awọn ondè le olori ẹṣọ́ lọwọ: ṣugbọn nwọn jọwọ Paulu ki o ma gbé fun ara rẹ̀ pẹlu ọmọ-ogun ti nṣe oluṣọ rẹ̀.

17 O si ṣe, lẹhin ijọ kẹta, Paulu pè awọn olori Ju jọ: nigbati nwọn si pejọ, o wi fun wọn pe, Alàgba, ará, a mọ̀ pe emi

Digitized by Google

kò ṣe ohun kan lọ́ si òdi si awọn enia, tabi
si iṣe awọn baba wa, ṣugbọn nwọn fi mi le
awọn ara Romu lọwọ li ondè lati Jerusale-
mu wá.
18 Nigbati nwọn si wádi ọ̀ran mi, ẹniti
iba jọwọ mi lọwọ lọ, nitoriti kò si ọ̀ran ikú
lara mi.
19 Ṣugbọn nigbati awọn Ju sọ̀rọ òdi si i,
nitorina ni mo ṣe fi ọ̀ran mi lọ Kesari ; kò
tilẹ ṣepe mo ni nkan lati fi orilẹ-ède mi
sùn si.
20 Nitorina ni mo si ṣe ranṣẹ pè nyin,
lati ri nyin, ati lati ba nyin sọ̀rọ : nitori
ireti Israeli li a ṣe fi ẹ̀wọn yi dè mi.
21 Nwọn si da a lohùn pe, Awa kò ri
iwe gbà lati Judea wá nitori rẹ, bẹ̃li awọn
arakọnrin ti o ti ibẹ̀ wá kò rò, bẹ̃ni nwọn
kò sọ̀rọ buburu kan si ọ.
22 Ṣugbọn awa nfẹ gbọ́ li ẹnu ara rẹ li
eyi ti iwọ nrò : nitori bi o ṣe ti iyapa ada-
mọ yi ni, awa mọ̀ pe, nibi gbogbo li a
nsọ̀rọ òdi si i.
23 Nigbati nwọn dá ọjọ fun u, ọ̀pọ ninu
wọn li o tọ̀ ọ wá ni ile àgbawọ rẹ̀ ; awọn
ẹniti o sọ itumọ̀ ati ọ̀rọ ijọba Ọlọrun fun,
o npa wọn ni iyè dà sipa ti Jesu, lati inu
ofin Mose, ati inu iwe awọn woli wá, lati
owurọ̀ titi o fi di aṣãlẹ.
24 Ẹlomiran si gbà ohun ti o nwi gbọ́
ẹlomiran kò si gbagbọ́.
25 Nigbati ohùn wọn kò ṣọkan ninu ara
wọn, nwọn tuká, nigbati Paulu sọ ọ̀rọ kan
pe, Nitõtọ li Ẹmí Mimọ́ sọ lati ẹnu woli
Isaiah wá fun awọn baba wa,
26 Wipe, Tọ̀ awọn enia wọnyi lọ, ki o
si wipe, Ni gbigbọ́ ẹnyin o gbọ́, kì yio si
yé nyin ; ati ni riri ẹnyin o ri, ẹnyin kì
yio si woye :
27 Nitoriti àiya awọn enia yi sebọ, eti
wọn si wuwo lati gbọ́, nwọn si dì oju wọn ;
nitori ki nwọn ki o má ba fi oju wọn ri, ki
nwọn ki o má ba fi etí wọn gbọ́, ati ki
nwọn ki o má ba fi àiya wọn mọ̀, ki nwọn
ki o má ba yipada, ati ki emi ki o má ba
mu wọn lara da.
28 Njẹ ki o yé nyin pe, a rán igbala
Ọlọrun si awọn Keferi, nwọn o si gbọ́.
29 Nigbati o si ti sọ ọ̀rọ wọnyi fun wọn,
awọn Ju lọ, nwon si ṣe aroye pipọ lọdọ ara
wọn.
30 Paulu si wà li ọdún mejì tọ̀tọ ni ile
àgbàwọ rẹ̀, o si ngbà gbogbo awọn ti o
wọle tọ̀ ọ wá,
31 O nwasu ijọba Ọlọrun, o si nfi igboi-
ya gbogbo kọ́ni li ohun wọnni ti iṣe ti
Jesu Kristi Oluwa, ẹnikan kò da a lẹkun.

---

EPISTELI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA ROMU.

## ORI 1.

PAULU, iranṣẹ Jesu Kristi, ti a pè ṣe
aposteli, ti a yàn si ọ̀tọ si ihin-rere
Ọlọrun,
2 (Ti o ti ṣe ileri tẹlẹ ri li ẹnu awọn woli
rẹ̀ ninu iwe-mimọ́,)
3 Nipa ti Ọmọ rẹ̀, (ti a bí ninu irú-ọmọ
Dafidi nipa ti ara ;
4 Ẹniti a fi ọlá pè li Ọmọ Ọlọrun, nipa
Ẹmí iwa mimọ́, nipa ajinde kuro ninu okú,)
Jesu Kristi Oluwa wa :
5 Nipa ọdọ ẹniti awa nri ore-ọfẹ ati iṣẹ
aposteli gbà, fun ifetisi igbagbọ́ ninu gbo-
gbo orilẹ-ède, nitori orukọ rẹ̀ :
6 Ninu ẹniti ẹnyin pẹlu di ẹni ìpe ti
Jesu Kristi :
7 Si gbogbo ẹniti o wà ni Romu, olufẹ
Ọlọrun, ti a pè li enia mimọ́ : Ore-ọfẹ si
nyin ati alafia lati ọdọ Ọlọrun Baba wa wá,
ati Jesu Kristi Oluwa.
8 Mo tète dupẹ na fun Ọlọrun mi fun
gbogbo nyin nipa Jesu Kristi, nitori ti a
nròhin igbagbọ́ nyin yi gbogbo aiye ká.
9 Ọlọrun sá li ẹlẹri mi, ẹniti emi nfi
ọkàn mi sìn ninu ihin-rere Ọmọ rẹ̀, pe li



Digitized by Google

aisimi li emi nranti nyin nigba-gbogbo
ninu adura mi;
10 Emi mbẹbẹ, bi yio le ṣe li asiwa-asi-
bọ bi emi o le ri ọ̀na rere nipa ifẹ Ọlọrun,
lati tọ̀ nyin wá.
11 Nitori ti emi nfẹ ri nyin, ki emi ki o
ta nyin li ọrẹ ẹmí, nitori ki ẹnyin ki o le
di ẹlẹsẹ-nilẹ;
12 Eyini ni, ki a jùmọ tù mi ninu pẹlu
nyin nipa igbagbọ́, ti nyin ati ti emi.
13 Ará, emi kò si fẹ ki ẹnyin ki o wà li
aimọ̀ pe, nigba-pipọ li emi npete rẹ̀ lati tọ̀
nyin wá, (ṣugbọn o di ẹtì fun mi di isisiyi,)
ki emi ki o le jẹ èrè diẹ ninu nyin pẹlu, bi
ti inu awọn Keferi miran.
14 Mo di ajigbese si awọn Hellene, ati
si awọn alaigbede; si awọn ọlọ́gbọn, ati si
awọn alaigbọn.
15 Niwọn bi o ti wà ni ipá mi, mo mura
tan lati wasu ihin-rere fun ẹnyin ara Romu
pẹlu.
16 Nitori emi kò tiju ihin-rere Kristi;
nitori agbara Ọlọrun ni si igbala fun olu-
kuluku ẹniti o gbagbọ́; fun Ju ṣaju, ati
fun Hellene pẹlu.
17 Nitori ninu rẹ̀ li ododo Ọlọrun gbé
farahàn lati igbagbọ́ de igbagbọ́: gẹgẹ bi a
ti kọ ọ pe, Olõtọ yio wà nipa igbagbọ́.
18 Nitori ibinu Ọlọrun hàn lati ọrun wá
si gbogbo ìwa buburu ati aiṣododo enia,
awọn ti o fi aiṣododo di otitọ mu;
19 Nitori ohun ti ã mọ̀ niti Ọlọrun o
farahàn ninu wọn; nitori Ọlọrun ti fi i hàn
fun wọn.
20 Nitori ohun rẹ̀ ti o ṣe alaihàn nigba
ati ọjọ ìwa a ri wọn nigbangba, a nfi oyé
ohun ti a dá mọ̀ ọ, ani agbara ati iwa-Ọlọ-
run rẹ̀ aiyeraiye, bẹ̃ni nwọn wà li airiwi:
21 Nitori igbati nwọn mọ̀ Ọlọrun, nwọn
kò yìn i logo bi Ọlọrun, bẹ̃ni nwọn kò si
dupẹ; ṣugbọn nwọn wa idi asan ni ironu
wọn, àiya wère wọn si di òkunkun.
22 Nwọn npè ara wọn li ọlọ́gbọn, nwọn
di aṣiwere,
23 Nwọn si pa ogo Ọlọrun ti kì idibajẹ
dà, si ere ti a ṣe bi enia ti idibajẹ, ati
ẹiyẹ, ati ẹranko ẹlẹsẹ mẹrin, ati ohun ti
nrakò.
24 Nitorina li Ọlọrun ṣe fi wọn fun ìwa-
ẽri nitori ifẹkufẹ ọkàn wọn, lati ṣe aibọ̀wọ
fun ara wọn larin ara wọn:
25 Ẹniti o pa otitọ Ọlọrun dà di eke,
nwọn si ntẹriba, nwọn si sìn ẹda jù Ẹlẹda
lọ, ẹniti iṣe olubukun titi lai. Amin.
26 Nitori eyiyi li Ọlọrun ṣe fi wọn fun
ifẹ buburu ọkàn: nitori awọn obirin wọn
tilẹ pa iṣe ti adanida dà si eyi ti a kò
danida:
27 Ati awọn ọkọnrin pẹlu, nwọn a mã
fi ilò obirin ti adan da silẹ, nwọn ama fẹ
ifẹkufẹ si ara wọn; ọkọnrin mba ọkọnrin
ṣe eyi ti kò yẹ, nwọn si njẹ èrè ìṣina wọn
ninu ara wọn bi o ti yẹ si.
28 Ati gẹgẹ bi nwọn kò ti fẹ ni ìro
Ọlọrun ni ìmọ wọn, Ọlọrun fi wọn fun iyè
rirà lati ṣe ohun ti ko tọ́:
29 Nwọn kún fun aiṣododo gbogbo,
àgbere, ìka, ojukòkoro, arankan; nwọn
kún fun ilara, ipania, agun, itanjẹ, iwa-
buburu; ajirọsọ,
30 Ẹlẹgàn, akorira Ọlọrun, afojudi,
aṣefẹfe, ahalẹ, adisi buburu, aṣaigbọran si
õbi,
31 Alainiyè ninu, atudimọ̀, alainiyọ́nu,
agídi, alailãnu:
32 Awọn ẹniti o mọ̀ idajọ Ọlọrun pe,
ẹniti o ba ṣe irú nkan wọnyi, o yẹ si ikú,
nwọn kò ṣe bẹ̃ nikan, ṣugbọn nwọn ni inu
didùn si awọn ti nṣe wọn.

## ORI 2.

NITORINA alairiwi ni iwọ ọkọnrin na,
ẹnikẹni ti o wù ki o ṣe ti ndajọ: ni-
tori ninu ohun ti iwọ nṣe idajọ ẹlomiran,
iwọ ndá ara rẹ lẹbi; nitori iwọ ti ndajọ
nṣe ohun na.
2 Ṣugbọn awa mọ̀ pe gẹgẹ bi otitọ ni
idajọ Ọlọrun si gbogbo awọn ti o nṣe irú
ohun ba wọnni.
3 Ati iwọ ọkọnrin na ti nṣe idajọ awọn
ti nṣe irú nkan wọnni, ti iwọ si nṣe bẹ̃ na,
iwọ ṣebi iwọ o yọ ninu idajọ Ọlọrun?
4 Tabi iwọ ngàn ọrọ̀ ore ati ipamọra ati
sũru rẹ̀; li aimọ̀ pe ore Ọlọrun li o nfà ọ lọ
si ironupiwada?
5 Ṣugbọn nipa lile ati aironupiwada
àiya rẹ, iwọ nfi ibinu ṣura fun ara rẹ dè
ọjọ ibinu ati dè ọjọ ifihàn idajọ ododo
Ọlọrun;
6 Ẹniti yio fifun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ
rẹ̀:
7 Fun awọn ti o nfi iyanju-duro ni rere-
iṣe, nwá iyìn ati ọlá ati aidibajẹ, ìye aini-
pẹkun;
8 Ṣugbọn fun awọn aṣagun, ti nwọn kò
si gbà otitọ gbọ́, ṣugbọn ti nwọn ngbà
aiṣododo gbọ́, irunu ati ibinu,
9 Ipọnju ati irora, ni fun gbogbo ọkàn
enia ti nṣe buburu, fun Ju ṣaju, ati fun
Hellene pẹlu;
10 Ṣugbọn ogo, ati ọlá, ati alafia, fun

Digitized by Google

gbogbo enia ti o nṣe rere, fun Ju ṣaju, ati fun Hellene pẹlu:

11 Nitori ojusaju enia kò si lọdọ Ọlọrun.

12 Nitori ìwọn awọn ti o ṣẹ̀ li ailofin, nwọn o si fi ailofin ṣegbé: ati ìwọn awọn ti o ṣẹ̀ ninu ofin, awọn li a o si fi ofin dajọ fun;

13 (Nitori kì iṣe alafetigbọ́ ofin ni iṣe alare niwaju Ọlọrun, ṣugbọn awọn alairufin li a o da lare.

14 Nitori igbati awọn Keferi, ti kò li ofin, ba ṣe ohun ti o wà ninu ofin nipa ti ẹda, awọn wọnyi ti kò li ofin, nwọn li ofin ninu ara wọn:

15 Ti o fi hàn pe, a ti kọwe iṣẹ ofin si wọn li àiya, imọ-ọkàn wọn si njẹri ninu ara wọn, ati ironu wọn ama fi wọn sùn, bikoṣe bẽ, nwọn ama ṣe ariwi fun ara wọn;)

16 Li ọjọ na nigbati Ọlọrun yio ti ọdọ Jesu Kristi dajọ aṣiri enia gẹgẹ bi ihin-rere mi.

17 Wò o, iwọ ti a npè ni Ju, ti iwọ si simi le ofin, iwọ si nṣogo ninu Ọlọrun,

18 Iwọ si mọ̀ ifẹ rẹ̀, iwọ si dán ohun ti o yàtọ wò, ẹniti a ti kọ li ofin;

19 Ti o si gbé oju le ara rẹ pe iwọ li amọ̀na afọju, imọlẹ awọn ti o wà li òkunkun,

20 Olukọ awọn alaimoye, olukọ awọn ọmọde, ẹniti o li àworan imọran ati otitọ ofin li ọwọ.

21 Njẹ iwọ ti o nkọ́ ẹlomiran, iwọ kò kọ́ ara rẹ? iwọ ti o nwasu ki enia ki o má jale? iwọ njale?

22 Iwọ ti o ni ki enia ki o máṣe panṣaga, iwọ nṣe panṣaga? iwọ ti o korira oriṣa, iwọ njà tempili lolè?

23 Iwọ ti nṣogo ninu ofin, ni riru ofin iwọ bù Ọlọrun li ọlá kù?

24 Nitori orukọ Ọlọrun sá di isọrọ-òdi si ninu awọn Keferi nitori nyin, gẹgẹ bi a ti kọ ọ.

25 Nitoriti ikọla li ère nitõtọ, bi iwọ ba pa ofin mọ́: ṣugbọn bi iwọ ba ṣe arufin, ikọla rẹ di aikọla.

26 Nitorina bi alaikọla ba pa ododo ofin mọ́, a kì yio ha kà aikọla rẹ̀ si ikọla bi?

27 Alaikọla nipa ti ẹda, bi o ba pa ofin mọ́, kì yio ha dajọ ẹbi fun iwọ nipa ti iwe ati ikọla ti o rufin?

28 Nitoriti on kì iṣe Ju, ti o hàn lode; bẹ̃ni kì iṣe ikọla ti o hàn lode ara:

29 Ṣugbọn Ju ti inu li on; ati ikọla ti àiya, nipa ti ẹmí, kì iṣe ti iwe; iyìn ẹniti kò si lọdọ enia, bikoṣe lọdọ Ọlọrun.

## ORI 3.

NJẸ anfani ki ha ni fun Ju? tabi ère kini ni ilàkikọ?

2 Pipọ nibi gbogbo: nitori pe awọn li a tèkekọ fi ọ̀rọ Ọlọrun le lọwọ.

3 Nitori kini bi awọn ẹlomiran kò gbagbọ́? aigbagbọ́ wọn ni yio sọ igbagbọ́ Ọlọrun dasan bi?

4 Ki a má ri i: ẹ jẹ ki Ọlọrun ki o ṣe olõtọ, ṣugbọn ki gbogbo enia ki o jẹ eke; gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Ki a le da ọ lare ninu ọ̀rọ rẹ, ati ki iwọ le ṣẹgun nigbati a ba mba Ọ wijọ.

5 Ṣugbọn bi aiṣododo wa ba nyìn ododo Ọlọrun, kili awa o wi? Ọlọrun ti ngbẹsan ha ṣe alaiṣododo bi? (Mo fi ṣe akawe bi ènia.)

6 Ki a má ri i: njẹ Ọlọrun yio ha ṣe le dajọ araiye?

7 Nitori bi otitọ Ọlọrun ba di pipọ si iyìn rẹ̀ nitori eke mi; ẽhaṣe ti a fi mba mi wijọ bi ẹlẹṣẹ mọ́ si?

8 Laikuku ṣe, (bi nwọn ti nfi ọ̀rọ buburu ròhin wa, ati bi awọn ẹlomiran ti ntẹnumọ́ pe, awa nwipe,) Ẹ jẹ ki a mã ṣe buburu, ki rere ki o le jade wá? awọn ẹniti ẹbi wọn tọ́.

9 Njẹ ki ha ni? awa ha sanjù wọn bi? Kò ri bẹ̃ rara: nitori awa ti pinnu rẹ̀ tẹlẹ pe ati awọn Ju ati awọn Hellene gbogbo li o wà labẹ ẹ̀ṣẹ;

10 Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Kò si ẹnikan ti iṣe olododo, kò si ẹnikan:

11 Kò si ẹniti oyé yé, kò si ẹniti o nwá Ọlọrun ri.

12 Gbogbo nwọn li o ti ṣìna, nwọn di alailere patapata; kò si ẹniti o nṣe rere, kò si ẹnikan.

13 Isà okú li ọfun wọn; ahọn wọn ni nwọn fi nṣe itanjẹ; oró pamọlẹ mbẹ labẹ ète wọn:

14 Ẹnu ẹniti o kún fun èpe ati fun ikorò:

15 Ẹsẹ wọn yara lati ta ẹ̀jẹ silẹ:

16 Iparun ati ipọnju wà li ọ̀na wọn:

17 Ọ̀na alafia ni nwọn kò si mọ̀:

18 Ẹru Ọlọrun kò si niwaju wọn.

19 Nisisiyi awa mọ̀ pe ohunkohun ti ofin wi, o wi fun awọn ti o wà labẹ ofin: ki gbogbo ẹnu ki o le pamọ́, ati ki gbogbo araiye ki o le di ẹlẹbi niwaju Ọlọrun.

20 Nitorina nipa iṣẹ ofin, kò si ẹniti a o da lare niwaju rẹ̀: nitori nipa ofin ni ìmọ ẹ̀ṣẹ.

21 Ṣugbọn nisisiyi ododo Ọlọrun hàn

Digitized by Google

laisi ofin, ti a njẹ li ẹrí nipa ofin ati nipa
awọn woli;
22 Ododo Ọlọrun na nipa igbagbọ́ Jesu
Kristi si gbogbo enia, ati lara gbogbo awọn
ti o gbagbọ́: nitori ti kò si ìyatọ:
23 Gbogbo wa li a sá ti ṣẹ̀, a si di àbuku
si ogo Ọlọrun;
24 Ẹniti a nda lare lọfẹ nipa ore-ọfẹ rẹ̀,
nipa idande ti o wà ninu Kristi Jesu:
25 Ẹniti Ọlọrun ti yàn tẹlẹ ṣe ètutu nipa
igbagbọ́ ninu ẹ̀jẹ rẹ̀, lati fi ododo rẹ̀ hàn
nipa ti idariji ẹ̀ṣẹ ti o ti kọja, ninu ipamọra
Ọlọrun;
26 Lati fi ododo rẹ̀ hàn ni igba isisiyi:
ki o le ṣe alare ati oludare ẹniti o gbà Jesu
gbọ́.
27 Ọna igbà ṣogo dà? A ti mu u kuro.
Nipa ofin wo? ni ti iṣẹ? Agbẹdọ: ṣugbọn
nipa ofin igbagbọ́.
28 Nitorina awa pari rẹ̀ si pe nipa igba-
gbọ́ li a nda enia lare laisi iṣẹ ti ofin.
29 Ọlọrun awọn Ju nikanṣoṣo ha ni? kì
iṣe ti awọn Keferi pẹlu? Bẹ̃ni, ti awọn
Keferi ni pẹlu:
30 Njẹ a ri i pe Ọlọrun kan ni, ti yio da
are fun awọn akọla nipa igbagbọ́, ati fun
awọn alaikọla nitori igbagbọ́.
31 Awa ha nsọ ofin dasan nipa igbagbọ́
bi? Ki a má ri i: ṣugbọn awa nfi idi ofin
mulẹ.

## ORI 4.

NJẸ kili awa o ha wi pe Abrahamu baba
wa ri nipa ti ara?
2 Biobaṣepe a da Abrahamu lare nipa
iṣẹ, o ni ibi ti iba gbé ma ṣogo; ṣugbọn kì
iṣe niwaju Ọlọrun.
3 Iwe-mimọ́ ha ti wi? Abrahamu gbà
Ọlọrun gbọ́, a si kà a si fun u li ododo.
4 Njẹ fun ẹniti o ṣiṣẹ a kò kà ère na si
ore-ọfẹ bikoṣe si gbese.
5 Ṣugbọn si ẹniti kò ṣiṣẹ, ti o si ngbà
ẹniti o nda enia buburu lare gbọ́, a kà
igbagbọ́ rẹ̀ si ododo.
6 Gẹgẹ bi Dafidi ti ṣapẹrẹ ibukún olu-
warẹ̀ na, ẹniti Ọlọrun kà ododo si li aiṣiṣẹ,
7 Wipe, Ibukún ni fun awọn ẹniti a
dari ẹ̀ṣẹ wọn jì, ati fun awọn ẹniti a bò
ẹ̀ṣẹ wọn mọlẹ.
8 Ibukún ni fun ọkọnrin na ẹniti Oluwa
kò kà ẹ̀ṣẹ si li ọrùn.
9 Ibukún yi ha wá fun awọn akọla nikan
ni, tabi fun awọn alaikọla pẹlu? nitoriti a
wipe, a kà igbagbọ́ si Abrahamu fun ododo.
10 Bawo li a ha kà a si i? nigbati o wà
ni ikọla tabi li aikọla? Kì iṣe ni ikọla
ṣugbọn bikoṣe li aikọla ni.
11 O si gbà àmi ikọla, èdidi iṣẹ ododo
igbagbọ́ ti o ni nigbati o wà li aikọla: ki o
le ṣe baba gbogbo awọn ti o gbagbọ́, bi a
kò tilẹ kọ wọn ni ilà; ki a le kà ododo si
wọn pẹlu:
12 Ati baba ikọla fun awọn ti kò si ninu
kìki awọn akọla nikan, ṣugbọn awọn ti
nrìn nipasẹ igbagbọ́ Abrahamu baba wa, ti
o ni li aikọla.
13 Nitori ileri fun Abrahamu tabi fun
irú-ọmọ rẹ̀ pe, on o ṣe arole aiye, kì iṣe
nipa ofin, bikoṣe nipa ododo igbagbọ́.
14 Nitori bi awọn ti nṣe ti ofin ba ṣe
arole, igbagbọ́ di asan, ileri si di alaili
agbara:
15 Nitori ofin ni iṣiṣẹ ibinu: ṣugbọn
nibiti ofin kò ba si, irufin kò si nibẹ̀.
16 Nitorina li o fi ṣe ti ipa igbagbọ́, ki
o le ṣe ti ipa ore-ọfẹ; ki ileri ki o le da
gbogbo awọn irú-ọmọ loju; kì iṣe awọn ti
ipa ofin nikan, ṣugbọn ati fun awọn ti inu
igbagbọ́ Abrahamu pẹlu; ẹniti iṣe baba
gbogbo wa,
17 (Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Mo ti fi ọ ṣe
baba orilẹ-ède pipọ,) niwaju ẹniti on gba-
gbọ́, Ọlọrun tikararẹ̀, ti o sọ okú di ãye, ti
o si pè ohun wọnni ti kò si bi ẹnipe nwọn
ti wà:
18 Nigbati ireti kò si, ẹniti o gbà ireti
gbọ́, ki o le di baba orilẹ-ède pipọ, gẹgẹ bi
eyi ti a ti wi pe, Bayi ni irú-ọmọ rẹ yio ri.
19 Ẹniti kò ṣe ailera ni igbagbọ́, kò rò
ti ara on tikararẹ̀ ti o ti kú tan, nigbati o
to bi ẹni ìwọn ọgọrun ọdún, ati kíku inu
Sara:
20 Kò ṣiyemeji si ileri Ọlọrun nipa
aigbagbọ́; ṣugbọn o le ni igbagbọ́, o nfi
ogo fun Ọlọrun;
21 Nigbati o si ti mọ̀ daju li ọkàn rẹ̀ pe,
ohun ti on ba ti leri, o si le ṣe e.
22 Nitorina li a si ṣe kà a si ododo fun u.
23 A kò sá kọ ọ nitori tirẹ̀ nikan pe, a
kà a si fun u;
24 Ṣugbọn bikoṣe fun wa pẹlu, ẹniti a o
si kà a si fun, bi awa ba gbà a gbọ́, ẹniti o
gbé Jesu Kristi Oluwa wa dide kuro ninu
okú;
25 Ẹniti a fi tọrẹ nitori ẹ̀ṣẹ wa, ti a si
jinde nitori idalare wa.

## ORI 5.

NJẸ bi a si ti nda wa lare nipa igbagbọ́,
awa ni alafia lọdọ Ọlọrun nipa Oluwa
wa Jesu Kristi:

Digitized by Google

2 Lọdọ ẹniti awa si gbé ri ọ̀na gbà nipa
igbagbọ́ si inu ore-ọfẹ yi ninu eyi ti awa
gbé duro, awa si nyọ̀ ni ireti ogo Ọlọrun.
3 Kì si iṣe bẹ̃ nikan, ṣugbọn awa si
nṣogo ninu wahalà pẹlu: awa mọ̀ pe wa-
hàla ni iṣiṣẹ sũru;
4 Ati sũru ni iṣiṣẹ iriri; ati iriri ni iṣiṣẹ
ireti:
5 Ireti kì si idojuti ni; nitori ti ifẹ
Ọlọrun ti tàn ká wa li àiya lati ọdọ Ẹmí
Mimọ́ wá ti a fifun wa.
6 Nitori igbati awa ti wà laili agbara, li
akokò na gẹ ni Kristi kú fun awọn enia
buburu.
7 Nitori o ṣọ̀wọn ki ẹnikan ki o to kú
fun olododo: ṣugbọn fun enia rere, bọya
ẹlomiran tilẹ le dába ati kú.
8 Ṣugbọn Ọlọrun fi iyìn ifẹ rẹ̀ hàn fun
wa, nipe nigbati awa wà li ẹlẹṣẹ, Kristi
kú fun wa.
9 Melomelo si ni, ti a da wa lare nisisiyi
nipa ẹjẹ rẹ̀, li a o si gbà wa là kuro ninu
ibinu nitori rẹ̀.
10 Njẹ bi, nigbati awa wà li ọtá, a mu
wa ba Ọlọrun làja nipa ikú Ọmọ rẹ̀, melo-
melo, nigbati a là wa ni ìja tan, li a o gbà
wa là nipa ìye rẹ̀.
11 Kì si iṣe bẹ̃ nikan, ṣugbọn awa nṣogo
ninu Ọlọrun nipa Jesu Kristi Oluwa wa,
lọdọ ẹniti awa gbé ti ri ìlaja gbà nisisiyi.
12 Nitori gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ ti ti ipa ọdọ enia
kan wọ̀ aiye, ati ikú nipa ẹ̀ṣẹ; bẹ̃ni ikú si
kọja lori enia gbogbo, lati ọdọ ẹniti gbogbo
enia ti dẹṣẹ:
13 Nitori ki ofin ki o to de, ẹ̀ṣẹ ti wà li
aiye: ṣugbọn a kò kà ẹ̀ṣẹ si nigbati ofin
kò si.
14 Ṣugbọn ikú jọba lati igbà Adamu wá
titi o fi de igba ti Mose, ati lori awọn ti kò
ṣẹ̀ bi afarawe iṣe Adamu, ti iṣe apẹrẹ ẹniti
mbọ̀.
15 Ṣugbọn kì iṣe bi ẹ̀ṣẹ bẹ̃ si li ẹ̀bun ọfẹ.
Nitori bi nipa ẹ̀ṣẹ ẹnikan, enia pipọ di
kíku, melomelo li ore-ọfẹ Ọlọrun, ati ẹ̀bun
nipa ore-ọfẹ ọkọnrin kan, Jesu Kristi, di
pipọ fun ọpọlọpọ.
16 Kì si iṣe pe bi ipa ti ẹnikan ti o ṣẹ̀,
li ẹ̀bun na: nitori idajọ ti ipasẹ ẹnikan
jade wá fun ẹbi, ṣugbọn ẹ̀bun ọfẹ ti inu
ẹ̀ṣẹ pipọ jade fun are.
17 Njẹ bi nipa ẹ̀ṣẹ ọkọnrin kan ikú jọba
nipa ẹnikan; melomelo li awọn ti ngbà
ọ̀pọlọpọ ore-ọfẹ, ati ti ẹ̀bun ododo, ti nwọn
o si jọba ninu ìye nipa ẹnikan, Jesu Kristi.
18 Njẹ bi nipa ẹ̀ṣẹ ẹnikan idajọ de bá
gbogbo enia si ẹbi; gẹgẹ bẹ̃ni nipa ododo
ẹnikan, ẹ̀bun ọfẹ de fun gbogbo enia ni
idalare si ìye.
19 Nitori gẹgẹ bi nipa aigbagbọ́ ẹnikan,
enia pipọ di ẹlẹṣẹ, bẹ̃ni nipa igbagbọ́ ẹni-
kan, a o sọ enia pipọ di olododo.
20 Pẹlupẹlu ofin bọ si inu rẹ̀, ki ẹ̀ṣẹ ki
o le di pipọ. Ṣugbọn nibiti ẹ̀ṣẹ gbé di
pipọ, ore-ọfẹ pọ̀ rekọja.
21 Gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ ti jọba ninu ikú, bẹ̃ si ni
ore-ọfẹ, ki o le jọba nipa ododo titi ìye ti
kò nipẹkun nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa.

ORI 6.

NJẸ awa o ha ti wi? Ki awa ki o ha
joko ninu ẹ̀ṣẹ, ki ore-ọfẹ ki o le ma
pọ̀ si i?
2 Ki a má ri i. Awa ẹniti o ti di okú
fun ẹ̀ṣẹ, awa o ha ti ṣe ti awa o fi wà ninu
rẹ̀ mọ́?
3 Ẹnyin kò mọ̀ pe, iye awọn ninu wa ti
a baptisi sinu Jesu Kristi, a baptisi wọn
sinu ikú rẹ̀?
4 Njẹ a si fi baptismu sin wa pọ̀ pẹlu rẹ̀
sinu ikú: pe gẹgẹ bi a ti jí Kristi Jesu dide
kuro ninu okú nipa ogo Baba, gẹgẹ bẹ̃li o
yẹ ki awa ki o ma rìn li ọtun ìwa.
5 Njẹ bi o ba ṣepe a gbìn wa pọ̀ ninu
afarawe ikú rẹ̀, awa o si ri bi afarawe
ajinde rẹ̀:
6 Eyi li awa si nmọ̀ pe, a kàn ogbologbo
ọkọnrin wa mọ agbelebu pẹlu rẹ̀, ki a le pa
ara ẹ̀ṣẹ run, lati isisiyi lọ ki a má le sìn
ẹ̀ṣẹ mọ́.
7 Nitori ẹniti o kú, o bọ́ lọwọ ẹ̀ṣẹ.
8 Njẹ bi awa ba bá Kristi kú, awa gba-
gbọ́ pe awa o si wà lãye pẹlu rẹ̀:
9 Awa mọ̀ pe bi a ti jí Kristi dide kuro
ninu okú, kò ni ikú mọ́; ikú kò le ṣe
oluwa rẹ̀ mọ́.
10 Nitori ti o kú, o di okú si ẹ̀ṣẹ lẹ̃kan:
nitori ti o si wà lãye, o wà lãye si Ọlọrun.
11 Bẹ̃ gẹgẹ ni ki ẹnyin ki o kà ara nyin
bi okú nitõtọ si ẹ̀ṣẹ, ṣugbọn ẹnyin wà lãye
si Ọlọrun nitori Jesu Kristi Oluwa wa.
12 Nitorina ẹ má jẹ ki ẹ̀ṣẹ ki o jọba li
ara okú nyin, lati gbà tirẹ̀ gbọ́ ninu ifẹkufẹ
rẹ̀.
13 Bẹ̃ni ki ẹnyin ki o máṣe jọwọ ẹ̀ya ara
nyin lọwọ bi ohun ìlo aiṣododo sinu ẹ̀ṣẹ;
ṣugbọn ẹnyin jọwọ ara nyin lọwọ fun
Ọlọrun, bi ẹniti o jinde kuro ninu okú, ati
ẹ̀ya ara nyin bi ohun ìlo ododo si Ọlọrun.
14 Nitori ẹ̀ṣẹ kì yio ṣe oluwa nyin: ni-
tori ẹnyin kò si labẹ ofin, bikoṣe labẹ ore-
ọfẹ.
15 Njẹ kini? ki awa ki o ha ma dẹṣẹ̀.

Digitized by Google

nitoriti awa kò si labẹ ọfin, bikọṣe labẹ
ore-ọfẹ? Ki a má ri i.
16 Ẹnyin kò mọ̀ pe, ẹniti ẹnyin ba fi ara
nyin le lọwọ bi ẹrú lati ma gbọ́ tirẹ̀, ẹrú
ẹniti ẹnyin ngbà tirẹ̀ gbọ́ li ẹnyin iṣe; iba
ṣe ti ẹ̀ṣẹ sinu ikú, tabi ti igbọran sinu
ododo?
17 Ṣugbọn ọpẹ́ ni fun Ọlọrun ti ẹnyin ti
ṣe ẹrú ẹ̀ṣẹ ri, ṣugbọn ẹnyin ti gbà aworan
ẹkọ́ na ti a fifun nyin gbọ́, lati inu ọkàn
nyin wá.
18 Njẹ bi a ti sọ nyin di omnira kuro
ninu ẹ̀ṣẹ, ẹnyin di ẹrú ododo.
19 Emi nsọ̀rọ yi bi ède enia nitori ailera
ara nyin: nitori bi ẹnyin ti jọwọ ẹ̀ya ara
nyin lọwọ li ẹrú fun ẽri ati sinu ẹ̀ṣẹ de ẹ̀ṣẹ;
bẹ̃ni ki ẹnyin ki o si jọwọ ẹ̀ya ara nyin
lọwọ li ẹrú si ododo si mimọ́ ìwa.
20 Nitori igbati ẹnyin ti nṣe ẹrú ẹ̀ṣẹ,
ẹnyin ti domnira ododo.
21 Njẹ ère kili ẹnyin ha jẹ ninu ohun ti
oju nti nyin si nisisiyi? nitori ikú li opin
nkan wọnni.
22 Ṣugbọn nisisiyi ti a sọ nyin di omnira
kuro ninu ẹ̀ṣẹ, ẹnyin si di ẹrú Ọlọrun,
ẹnyin njẹ ère nyin si mimọ́ ìwa, ati opin
rẹ̀ ìye ti kò nipẹkun.
23 Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn ẹ̀bun
ọfẹ Ọlọrun ni ìye ti kò nipẹkun, ninu Jesu
Kristi Oluwa wa.

## ORI 7.

ARÁ, ẹnyin kò mọ̀, (nitori awọn ti o mọ̀
ofin li emi mba wi,) bi ofin ti iṣe
oluwa enia ni ìwọn igbati o ba wà lãye?
2 Nitori obirin ti o wá lọdọ ọkọ, ìwọn
igbati ọkọ na wà lãye, a fi ofin dè e mọ́
ọkọ na; ṣugbọn bi ọkọ na ba kú, a tú u
silẹ kuro ninu ofin ọkọ na.
3 Njẹ bi o ba ṣepe, nigbati ọkọ rẹ̀ wà
lãye, bi a ba gbé e niyawo fun ọkọ miran,
panṣaga li a o ma pè e: ṣugbọn bi ọkọ rẹ̀
ba kú, o bọ lọwọ ofin na; ki iṣe panṣaga
bi a gbé e niyawo fun ọkọ miran.
4 Bẹ̃li ẹnyin ará mi, ẹnyin pẹlu ti di
okú si ofin nipa ara Kristi; ki a le gbé
nyin niyawo fun ẹlomiran, fun ẹniti a jinde
kuro ninu okú, ki awa ki o le so eso fun
Ọlọrun.
5 Nitori igbati awa wà ni ipa ti ara, ìfa
ọkàn ẹ̀ṣẹ, ti o wà nipa ofin, o nṣiṣẹ li ẹ̀ya
ara wa lati so eso si ikú.
6 Ṣugbọn nisisiyi a gbà wa lọwọ ofin,
awa si ti kuro ninu eyi ti o gbé wa dè; ki
awa ki o le ma sìn li ọtun ẹmí, li aiṣe ogbo-
logbo iwe.
7 Njẹ awa o ha ti wi? Ẹ̀ṣẹ ha li ofin bi?
Ki a má ri i. Ṣugbọn emi kò ti mọ̀ ẹ̀ṣẹ,
bikoṣepe nipa ofin: emi kò sá ti mọ̀ ifẹ-
kufẹ, bikoṣe bi ofin ti wi pe, Iwọ kò gbọdọ
ṣojukòkoro.
8 Ẹ̀ṣẹ si nti ipa ofin fẹ ẹ̀fẹ, o nṣe onirũru
ifẹkufẹ ninu mi. Nitori laisi ofin ẹ̀ṣẹ ti
kú.
9 Mo sá ti wà lãye laisi ofin nigbakan:
ṣugbọn nigbati ofin de, ẹ̀ṣẹ di ãye, emi si
kú.
10 Ofin ti o jẹ ti ìye, li emi si wa ri pe
o di ti iku.
11 Nitorina ẹ̀ṣẹ nipasẹ ofin o nfẹ ẹfẹ, o
tàn mi jẹ, nipasẹ rẹ̀ o lù mi pa.
12 Bẹ̃ni mimọ́ li ofin, mimọ́ si li aṣẹ, ati
ododo, ati didara.
13 A ha sọ ohun didara di ikú fun mi
bi? Ki a má ri i, ṣugbọn ẹ̀ṣẹ, ki o le hàn
li ẹ̀ṣẹ, nipa eyi ti o dara, o nṣiṣẹ ikú ninu
mi; ki ẹ̀ṣẹ nipa ofin ki o le di buburuju.
14 Nitori awa mọ̀ pe ohun ẹmí li ofin:
ṣugbọn ẹlẹran-ara li emi, ti a tà sabẹ
ofin.
15 Nitori ohun ti emi nṣe emi kò mọ̀:
nitori eyi ti mo fẹ emi kò ṣe; ṣugbọn eyi
ti mo korira, eyini li emi nṣe.
16 Njẹ bi mo ba nṣe eyi ti emi kò fẹ,
mo li ohun si ofin pe o dara.
17 Njẹ nisisiyi kì iṣe emi li o nṣe e mọ́,
bikoṣe ẹ̀ṣẹ ti o wà li ara mi.
18 Nitori emi mọ̀ pe ninu mi (eyini ni
pe li ara mi,) kò si nkan ti o dara: atifẹ
sá wà li ọkàn mi; ṣugbọn lati ṣe eyi ti o
dara, emi kò ri.
19 Nitori ire ti emi fẹ emi kò ṣe: ṣu-
gbọn buburu ti emi kò fẹ, eyini li emi
nṣe.
20 Njẹ bi mo ba nṣe eyi ti emi kò fẹ,
emi ki nṣe e mọ́, bikoṣe ẹ̀ṣẹ ti o wà ninu
mi.
21 Njẹ mo ri ofin kan, nigbati emi ba
nfẹ ṣe rere, buburu a si ma wà lọdọ mi.
22 Inu mi sá dùn si ofin Ọlọrun nipa ti
ọkọnrin inu:
23 Ṣugbọn mo ri ofin miran li ẹ̀ya ara
mi, o mba ofin inu mi jà, o si ndì mi ni
igbekun wa fifun ofin ẹ̀ṣẹ, ti o wà li ẹ̀ya
ara mi.
24 Emi ọkọnrin òṣi! tani yio ha gbà
mi lọwọ ara ikú yi?
25 Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun nipasẹ Jesu
Kristi Oluwa wa. Njẹ bẹ̃li emi tikara mi
nfi inu sìn ofin Ọlọrun; ṣugbọn nfi ara sìn
ofin ẹ̀ṣẹ.

Digitized by Google

## ORI 8.

NJẸ ẹbi kò si mọ́ nisisiyi fun awọn ti o
wà ninu Kristi Jesu, ẹniti kò rìn ni
ipa ti ara, bikoṣe ni ipa ti Ẹmí.
2 Nitori ofin Ẹmí iye ninu Kristi Jesu,
ti gbà mi kuro lọwọ ofin ẹ̀ṣẹ ati ti ikú.
3 Nitori eyi ti ofin kò le ṣe, nitori ailera
rẹ̀ nipa ti ara, Ọlọrun rán Ọmọ rẹ̀ li
aworan ara ẹ̀ṣẹ, ati nipa ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ, li o da
ẹ̀ṣẹ lẹbi ninu ara.
4 Ki a le mu ododo ofin ṣẹ ninu wa,
ẹniti kò tọ̀ ipa ti ara, bikoṣe ipa ti Ẹmí.
5 Nitori awọn ti o wà ni ipa ti ara,
nwọn ama tọju ohun ti ara; ṣugbọn awọn
ti ntọ̀ ipa ti Ẹmí, nwọn ama tọju ti Ẹmí.
6 Nitori itọju ti ara ni ikú; ṣugbọn
itọju ti Ẹmí on li ĩye ati alafia:
7 Nitori itọju ti ara ọtá ni si Ọlọrun:
nitori kò foribalẹ fun ofin Ọlọrun, on kò
tilẹ le ri bẹ̃,
8 Bẹ̃li awọn ti o wà ninu ti ara, kò le
wù Ọlọrun.
9 Ṣugbọn ẹnyin kò si ninu ti ara, bi-
koṣe ninu ti Ẹmí, bi o ba ṣe pe Ẹmí Ọlọrun
wà ninu nyin. Bi ẹnikẹni kò ba si li Ẹmí
Kristi, kò si ninu ẹni tirẹ̀.
10 Bi Kristi ba si wà ninu nyin, ara a
kú nitori ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn Ẹmí a wà lãye
nitori ododo.
11 Njẹ bi Ẹmí ẹniti o jí Jesu dide kuro
ninu okú ba wà ninu nyin, ẹni na ti o jí
Kristi dide kuro ninu okú yio si fi Ẹmí
rẹ̀ ti o wà ninu nyin, sọ ara okú nyin di
ãye.
12 Njẹ ẹnyin ará, ajigbese li awa, kì iṣe
ti ara, ti a o fi wà ni ti ara.
13 Nitori bi ẹnyin ba wà ni ti ara,
ẹnyin o kú: ṣugbọn nipa ti Ẹmí bi ẹnyin
ba pa iṣe ti ara run, ẹnyin o yè.
14 Nitori iye awọn ti a nṣe amọ̀na fun
lati ọdọ Ẹmí Ọlọrun wá, awọn ni iṣe ọmọ
Ọlọrun.
15 Nitori ẹnyin kò gbà ẹmí ẹrú lati
bẹ̀ru mọ́; ṣugbọn ẹnyin ti gbà Ẹmí isọ-
dọmọ, nipa eyi ti awa fi nkepè, Abba,
Baba.
16 Ẹmí tikararẹ̀ li o njẹ ẹmí wa li ẹri
pe, ọmọ Ọlọrun li awa iṣe:
17 Bi awa ba ṣe ọmọ, njẹ awa li ajogun;
ajogun ti Ọlọrun, ati ajumọ-jogun pẹlu
Kristi; bi o ba ṣepe awa bá a jìya, ki a le
ṣe wa logo pẹlu rẹ̀.
18 Nitori mo ti ṣirò rẹ̀ pe, ìya igba
isisiyi kò yẹ lati fi ṣe akawe ogo ti a o fihàn
ninu wa.
19 Nitori afojusọ́na ireti ti ẹda o duro
dè ifihàn awọn ọmọ Ọlọrun,
20 Nitori a da ẹda lati foribalẹ fun asan,
ki iṣe tinutinu rẹ̀, ṣugbọn nitori ẹniti o nfi
ori rẹ̀ balẹ ni ireti,
21 Nitori a o yọ ẹda tikararẹ̀ kuro lọwọ
idibajẹ, sinu idande awọn ọmọ Ọlọrun ti o
li ogo.
22 Nitori awa mọ̀ pe gbogbo ẹda li o
nkerora ti o si nrọbi pọ titi o fi di isisiyi.
23 Kì si iṣe awọn nikan, ṣugbọn awa
tikarawa pẹlu, ti o ni akọso Ẹmí, ani awa
tikarawa nkerora ninu ara wa, awa nduro
dè isọdọmọ, idande ara wa.
24 Nitori nipa ireti li a fi ngbà wa là:
ṣugbọn ireti ti a ri kì iṣe ireti: nitori tani
ireti fun ohun ti o ti ri?
25 Ṣugbọn bi awa ba nreti eyi-ti awa kò
ri, njẹ awa ama fi sũru duro dè e.
26 Bẹ̃ gẹgẹ li Ẹmí pẹlu nràn ailera wa
lọwọ: nitori awa kò mọ̀ ohun ti awa iba
ma gbadura fun bi o ti yẹ fun wa: ṣugbọn
Ẹmí tikararẹ̀ nfi irora ti a kò le fi ẹnu sọ
bẹ̀bẹ fun wa.
27 Ati ẹniti nwadi inu ọkàn, o mọ̀ inu
Ẹmí, nitoriti o mbẹ̀bẹ fun awọn enia
mimọ́ bi ti inu Ọlọrun.
28 Awa si mọ̀ pe ohun gbogbo li o nṣiṣẹ
pọ̀ si rere fun awọn ẹniti o fẹ Ọlọrun, awọn
ẹni ìpe nipa ipinnu tirẹ̀.
29 Nitori awọn ẹniti o ti mọ̀ tẹlẹ, o si ti
yàn tẹlẹ lati faramọ aworan Ọmọ rẹ̀, ki o
le ṣe akobi ninu awọn arakọnrin pipọ.
30 Pẹlupẹlu awọn ẹniti o ti yàn tẹlẹ
awọn li o si pè: awọn ẹniti o si pè, awọn
li o si dalare: awọn ẹniti o si dalare, awọn
li o si ṣe logo.
31 Njẹ kili awa o ha wi si nkan wọnyi?
Bi Ọlọrun ba ṣe ti wa, tali o ha le kọju-
jasi wa?
32 Ẹniti kò da Ọmọ rẹ̀ si, ṣugbọn ti o fi
i fun gbogbo wa, yio ha ti ṣe ti kì yio fun
wa li ohun gbogbo lọfẹ pẹlu rẹ̀?
33 Tani yio ha kà ohunkohun si ọrùn
awọn ayanfẹ Ọlọrun? Ọlọrun li o ndare.
34 Tali o ndẹbi? Kristi ti o kú, ki a
sá kuku wipe, ti o jinde, ẹniti o si wà
li ọwọ́ ọtún Ọlọrun, ti o si mbẹ̀bẹ fun
wa.
35 Tani yio ha yà wa kuro ninu ifẹ
Kristi? ipọnju, tabi wahalà, tabi inuni-
bini, tabi ìyan, tabi ìhoho, tabi ewu, tabi
idà?
36 Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Nitori rẹ li a ṣe
npa wa kú li ọjọ gbogbo; a nkà wa si bi
agutan fun pipa.

Digitized by Google

37 Ṣugbọn ninu gbogbo nkan wọnyi awa
jù ẹniti o ṣẹgun lọ nipa ẹniti o fẹ wa.
38 Nitori emi mọ̀ ninu mi pe, kì iṣe
ikú, kì iṣe ìye, tabi awọn angeli, tabi awọn
ijoye, tabi awọn alagbara, tabi ohun ìgba
isisiyi, tabi ohun ìgba ti mbọ̀.
39 Tabi òke, tabi ọgbun, bẹ̃ni kì iṣe ẹda
miran, ti o le yà wa kuro ninu ifẹ Ọlọrun,
ti o wà nipa Kristi Jesu Oluwa wa.

## ORI 9.

OTITỌ li emi nsọ ninu Kristi, emi kò
ṣeke, ọkàn mi si njẹ mi li ẹrí ninu
Ẹmí Mimọ́,
2 Pe ibinujẹ mi pọ̀, ati ikãnu nigba-
gbogbo li ọkàn mi.
3 Nitori emi nfẹ pe ki a yà emi tikarami
kuro lọdọ Kristi, nitori awọn ará mi, awọn
ibatan mi nipa ti ara:
4 Awọn ẹniti iṣe ará Israeli; ti ẹniti
isọdọmọ iṣe, ati ogo, ati majẹmu, ati isofin,
ati ìsin Ọlọrun, ati ileri;
5 Ti ẹniti awọn baba iṣe, ati ninu ẹniti
Kristi ti wá nipa ti ara, ẹniti o bori ohun
gbogbo, Ọlọrun olubukún lailai. Amin.
6 Nitori kì iṣe bi ẹnipe ọ̀rọ Ọlọrun kò
kuku ṣe nkan rara. Kì sá iṣe gbogbo awọn
ti o ti inu Israeli jade, awọn ni Israeli:
7 Bẹ̃ni kì iṣe pe nitori nwọn ṣe irú-ọmọ
Abrahamu, gbogbo wọn li ọmọ: ṣugbọn,
Lọdọ Isaaki li a o ti pè irú-ọmọ rẹ.
8 Eyini ni pe, Awọn ti iṣe ọmọ nipa ti
ara, awọn wọnni kì iṣe ọmọ Ọlọrun: ṣu-
gbọn awọn ọmọ ileri li a o kà ni irú-ọmọ.
9 Nitori eyi li ọ̀rọ ileri, Li akokò yi li
emi mbọ̀, Sara yio si li ọmọ ọkọnrin.
10 Kì si iṣe kìki eyi; ṣugbọn igbati
Rebekka pẹlu lóyun fun ẹnikan, fun Isaaki
baba wa;
11 Nitori awọn ọmọ ti a kò ti ibí, bẹ̃ni
nwọn kò ti iṣe rere tabi buburu, (ki ipinnu
Ọlọrun nipa iyanfẹ ki o le duro, kì iṣe nipa
ti iṣẹ, bikoṣe ti ẹni ti npè-ni;)
12 A ti sọ fun u pe, Ẹgbọn ni yio ma
sìn aburo.
13 Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Jakọbu ni mo
fẹ, ṣugbọn Esau ni mo korira.
14 Ewo li awa o ha wi? Aiṣododo ha
wà lọdọ Ọlọrun bi? Ki a má ri i.
15 Nitori o wi fun Mose pe, Emi o ṣãnu
fun ẹniti emi o ṣãnu fun, emi o si ṣe iyọ́nu
fun ẹniti emi o ṣe iyọ́nu fun.
16 Njẹ bẹ̃ni kì iṣe ti ẹniti o fẹ, kì si iṣe
ti ẹniti nsáre, bikoṣe ti Ọlọrun ti nṣãnu.
17 Nitori iwe mimọ́ wi fun Farao pe,
Nitori eyiyi na ni mo ṣe gbé ọ dide, ki emi
ki o le fi agbara mi hàn lara rẹ, ki a si le
ma ròhin orukọ mi ká aiye gbogbo.
18 Nitorina li o ṣe nṣãnu fun ẹniti o wù
u, ẹniti o wù u a si mu u li ọkàn le.
19 Iwọ o si wi fun mi pe, Kili o ha nfẹ
ẹ̀fẹ si? Nitori tali o ha ndè ifẹ rẹ̀ lọna?
20 Bẹ̃kọ, Enia, tani iwọ ti nda Ọlọrun
lohùn? Ohun ti a mọ ama da ẹniti o mọ
ọ lohùn pe, Ẽṣe ti iwọ fi mọ-mi bayi?
21 Amọ̀koko kò ha kawọ amọ̀, ninu ìṣu
kanna lati ṣe ohun ìlo kan si ọlá, ati ohun
ìlo miran si ailọlá?
22 Njẹ bi Ọlọrun nfẹ fi ibinu rẹ̀ hàn, ti
o si nfẹ fi agbara rẹ̀ hàn nkọ́, ti o si mu
suru fun ohun ìlo ibinu ti a mọ fun iparun:
23 Ati ki o le fi ọrọ̀ ogo rẹ̀ hàn lara ohun
ìlo ãnu rẹ̀, ti o ti pèse ṣaju fun ogo,
24 Ani awa, ti o ti pè, kì iṣe ninu awọn
Ju nikan, ṣugbọn ninu awọn Keferi pẹlu?
25 Bi o ti wi pẹlu ni Hosea pe, Emi o
pè awọn ti kì iṣe enia mi, li enia mi; ati
olufẹ rẹ̀ ti kì ti iṣe olufẹ.
26 Yio si ṣe, ni ibi ti a gbé sọ fun wọn
pe, Ẹnyin kì iṣe enia mi, nibẹ̀ li a o gbé
pè wọn li ọmọ Ọlọrun alãye.
27 Isaiah si ké nitori Israeli pe, Bi iye
awọn ọmọ Israeli tilẹ ri bi iyanrin okun, a
o gbà apakan là:
28 Nitori yio pari iṣẹ na, yio si fi ododo
ke iṣẹ rẹ̀ kúru: nitori iṣẹ kúkuru li Oluwa
o ṣe li aiye.
29 Ati bi Isaiah ti wi tẹlẹ, Bikoṣepe bi
Oluwa awọn Ọmọ-ogun ti fi irú-ọmọ silẹ
fun wa, awa iba ti dabi Sodomu, a ba si ti
sọ wa dabi Gomora.
30 Njẹ kili awa o ha wi? Pe awọn
Keferi, ti kò tọ̀ ipa ododo, ọwọ́ wọn tẹ̀
ododo, ani ododo na ti o ti inu igbagbọ́
wá.
31 Ṣugbọn Israeli ti ntọ̀ ipa ofin ododo,
ọwọ́ wọn kò tẹ̀ ofin ododo.
32 Nitori kini? nitori nwọn ko tọ̀ ipa
igbagbọ́, ṣugbọn bi ẹnipe ipa iṣẹ ofin. Ni-
torina ni nwọn ṣe ndugbolu okuta idugbolu
nì;
33 Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Kiyesi i, mo
gbé okuta idugbòlu ati àpata ikọsẹ̀ kalẹ ni
Sioni: ẹnikẹni ti o gbà tirẹ̀ gbọ́ kì yio
damu.

## ORI 10.

ARÁ ifẹ ọkàn mi, ati adura mi si Ọlọrun
fun Israeli ni, ki a le gbà wọn là.
2 Nitori mo gbà ẹri wọn jẹ pe, nwọn ni
itara fun Ọlọrun, ṣugbọn kì iṣe nipa ìmọ.

Digitized by Google

3 Nitori nwọn ṣe alaimọ̀ ododo Ọlọrun,
nwọn nlọ lati gbé ododo ara wọn kalẹ,
nwọn kò si foribalẹ fun ododo Ọlọrun.
4 Nitori Kristi li opin ofin si ododo fun
olukuluku ẹniti o gbagbọ́.
5 Mose sá ti ṣapẹrẹ ododo ti o wà nipa
ofin, pe ẹniti o ba ṣe nkan wọnni on ni
yio yè nipa wọn.
6 Ṣugbọn ododo ti o wà nipa igbagbọ́ sọ
bayi pe, Máṣe wi li ọkàn rẹ pe, tani yio lọ
soke ọrun? (eyini ni, lati mu Kristi sọ-
kalẹ:)
7 Tabi, tani yio sọkalẹ lọ si ọgbun?
(eyini ni, lati mu Kristi ti inu okú wá
soke.)
8 Ṣugbọn kili o wi? Ọ̀rọ na wà leti
ọdọ rẹ, ati li ẹnu rẹ, ati li àiya rẹ: eyini
ni, ọ̀rọ igbagbọ́, ti awa nwasu;
9 Pe bi iwọ ba fi ẹnu rẹ jẹwọ Jesu Olu-
wa, ti iwọ si gbagbọ́ li ọkàn rẹ pe, Ọlọrun
ji i dide kuro ninu okú, a o gbà ọ là.
10 Nitori ọkàn li enia ifi gbagbọ́ si
ododo; ẹnu li a si fi jẹwọ si igbala.
11 Nitori iwe-mimọ́ wipe, Ẹnikẹni ti o
ba gbà a gbọ́ kì yio dãmu.
12 Nitori kò si iyatọ ninu Ju ati Hel-
lene: nitori Oluwa kanna li o lọrọ̀ fun
gbogbo awọn ti npè orukọ rẹ̀.
13 Ẹnikẹni ti o ba sá pè orukọ Oluwa,
li a o gbàlà.
14 Nwọn o ha ti ṣe pè orukọ ẹniti nwọn
kò gbagbọ́? nwọn o ha ti ṣe gbà ẹniti
nwọn kò gburó rẹ̀ ri gbọ́? nwọn o ha ti ṣe
gbọ́ laini oniwasu?
15 Nwọn o ha ti ṣe wasu, bikoṣepe a
rán wọn? gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Ẹsẹ awọn
ti nwasu ihin-rere alafia ti dara to, awọn
ti nwãsu ihin ayọ̀ ohun rere!
16 Ṣugbọn gbogbo wọn kò gbà ihin-rere
gbọ́. Isaiah sá wipe, Oluwa, tali o gbà
iwasu wa gbọ́?
17 Njẹ nipa igbọran ni igbagbọ́ ti wá,
ati igbọran nipa ọ̀rọ Ọlọrun.
18 Ṣugbọn mo ni, Awọn kò ha gbọ́ bi?
Nitõtọ, ohùn wọn jade lọ si gbogbo ilẹ, ati
ọ̀rọ wọn si opinlẹ aiye.
19 Ṣugbọn mo ni, Israeli kò ha mọ̀ bi?
Mose tète wipe, Emi o fi awọn ti kì iṣe
enia mu nyin jowú, ati awọn alaimoye
enia li emi o fi bi nyin ninu.
20 Ṣugbọn Isaiah tilẹ laiya, o si wipe,
A ri mi lọdọ awọn ti kò wá mi kiri; awọn
ti kò bère mi li a fi mi hàn fun.
21 Ṣugbọn fun Israeli li o wipe, Li ọjọ
gbogbo li emi nnà ọwọ́ mi si awọn alai-
gbọran ati alariwisi enia.

## ORI 11.

NJẸ mo ni, Ọlọrun ha ta awọn enia rẹ̀
nù bi? Ki a má ri i. Nitori ara
Israeli li emi pẹlu, ninu irú-ọmọ Abra-
hamu, li ẹ̀ya Benjamini.
2 Ọlọrun kò ta awọn enia rẹ̀ nù ti o ti
mọ̀ tẹlẹ. Tabi ẹnyin kò mọ̀ bi iwe-mimọ́
ti wi niti Elijah? bi o ti mbẹ̀bẹ lọdọ Ọlọ-
run si Israeli, wipe,
3 Oluwa, nwọn ti pa awọn woli rẹ tan,
nwọn si ti wó pẹpẹ rẹ lulẹ; emi nikanṣoṣo
li o si kù, nwọn si ndọdẹ ẹmí mi kiri.
4 Ṣugbọn èsi Ọlọrun ti wi fun u? Mo
ti pa ẹdẹgbarin enia mọ́ fun ara mi, ti kò
fi ẽkun balẹ fun Baali.
5 Gẹgẹ bẽ si ni li akokò isisiyi, apakan
wà nipa ti iyanfẹ ore-ọfẹ.
6 Bi o ba si ṣepe nipa ti ore-ọfẹ, njẹ kì
iṣe ti iṣẹ mọ́: ayamọbi ore-ọfẹ kì iṣe ore-
ọfẹ mọ́. Ṣugbọn biobaṣepe nipa ti iṣẹ ni,
njẹ kì iṣe ti ore-ọfẹ mọ́: ayamọbi iṣẹ kì
iṣe iṣẹ mọ́.
7 Ki ha ni? Israeli kò ri ohun ti nwá
kiri; ṣugbọn awọn ẹni iyanfẹ ti ri i, awọn
iyokù si fọju.
8 (Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Ọlọrun ti fun
wọn li ẹmí orun, oju ki nwọn ki o má le
riran, ati etí ki nwọn ki o má le gbọran;)
titi o fi di oni-oloni.
9 Dafidi si wipe, Jẹ ki tabili wọn ki o
di idẹkun, ati ẹgẹ́, ati ohun ikọsẹ̀, ati ẹsan
fun wọn:
10 Ki oju wọn ki o ṣú, ki nwọn ki o
má le riran, ki o si tẹ̀ ẹhin wọn ba nigba-
gbogbo.
11 Njẹ mo ni, Nwọn ha kọsẹ̀ ki nwọn
ki o le ṣubu? Ki a má ri i: ṣugbọn nipa
iṣubu wọn ki igbala ki o le de ọdọ awọn
Keferi, lati mu wọn jowú.
12 Njẹ bi iṣubu wọn ba di ọrọ̀ aiye, ati
bi ikekuro wọn ba di ọrọ̀ awọn Keferi;
melomelo ni kíkún wọn?
13 Ẹnyin Keferi li emi sá nsọ fun, ni-
tori aposteli awọn Keferi li emi iṣe, mo
gbé oyè mi ga:
14 Bi yio le ṣe ki emi ki o le mu awọn
ará mi jowú, ki emi ki o le gbà diẹ là ninu
wọn.
15 Njẹ bi titanù wọn ba di ìlaja aiye,
gbigbà wọn yio ha ti ri, bikoṣe yiyè kuro
ninu okú?
16 Njẹ bi akọso ba mọ́, bẽli akojọpọ:
bi gbòngbo ba mọ́, bẽ si li ẹká rẹ̀ na.
17 Bi a si yà awọn ẹká miran kuro, ti a
si lọ́ iwọ, ti iṣe igi oróro igbẹ́ sara wọn, ti



Digitized by Google

iwọ si*mba wọn pín gbòngbo ati oje igi
oróro na;
18 Máṣe fefé si awọn ẹká na. Ṣugbọn
bi iwọ ba nṣe fefé, iwọ kọ́ rù gbòngbo, ṣu-
gbọn gbòngbo li o rù iwọ.
19 Iwọ o si wipe, A ti fà awọn ẹká na
ya, nitori ki a le lọ́ mi sinu rẹ̀.
20 O dara; nitori aigbagbọ́ li a ṣe fà wọn
ya kuro, iwọ si duro nipa igbagbọ́. Máṣe
gbé ara rẹ ga, ṣugbọn bẹ̀ru:
21 Nitori bi Ọlọrun kò ba da ẹka-iyẹka
si, kiyesara ki o máṣe alaida iwọ na si.
22 Sa wo ore ati ikannu Ọlọrun: lori
awọn ti o ṣubu, ikannu; ṣugbọn lori iwọ,
ore, bi iwọ ba duro ninu ore rẹ̀: ki a má
ba ke iwọ na kuro.
23 Ati awọn pẹlu, bi nwọn kò ba joko
sinu aigbagbọ́, a o lọ́ wọn sinu rẹ̀: nitori
Ọlọrun le tún wọn lọ́ sinu rẹ̀.
24 Nitori bi a si ti ke iwọ lara igi oróro
igbọ́ nipa ẹda rẹ, ti a si lọ́ iwọ sinu igi
oróro rere lodi si ti ẹda: melomelo li a o
lọ́ awọn wọnyi, ti iṣe ẹka-iyẹka sara igi
oróro wọn?
25 Ará, emi kò sá fẹ ki ẹnyin ki o wà li
òpe niti ohun ijinlẹ yi, ki ẹnyin má ba ṣe
ọlọ́gbọn li oju ara nyin; pe ifọju bá Israeli
li apakan, titi kíkún awọn Keferi yio fi
de.
26 Bẹ̃li a o si gbà gbogbo Israeli là; bi
a ti kọ ọ pe, Ni Sioni li Olugbala yio ti
jade wá, yio si yi ìwa buburu pada kuro
lọdọ Jakọbu:
27 Eyi si ni majẹmu mi fun wọn, ni-
gbati emi o mu ẹ̀ṣẹ wọn kuro.
28 Nipa ti ihin-rere, ọtá ni nwọn nitori
nyin: bi o si ṣe ti iyanfẹ ni, olufẹ ni nwọn
nitori ti awọn baba.
29 Nitori aironupiwada li ẹ̀bun ati ìpe
Ọlọrun.
30 Nitori gẹgẹ bi ẹnyin kò ti gbà Ọlọ-
run gbọ́ nigba atijọ, ṣugbọn ti ẹnyin ri ãnu
gbà nisisiyi nipa aigbagbọ́ wọn:
31 Gẹgẹ bẹ̃li awọn wọnyi ti kò gbagbọ́
nisisiyi, ki nwọn ki o le ri ãnu gbà pẹlu
nipa ãnu ti a fi hàn nyin.
32 Nitori Ọlọrun sé gbogbo wọn pọ̀ sinu
aigbagbọ̀, ki o le ṣãnu fun gbogbo wọn.
33 A! ijinlẹ ọrọ̀ ati ọgbọ́n ati ìmọ
Ọlọrun! awamáridi idajọ rẹ̀ ti ri, ipa-ọ̀na
rẹ̀ si jù awari lọ!
34 Nitori tali o mọ̀ inu Oluwa? tabi
tani iṣe ìgbimọ rẹ̀?
35 Tabi tali o tète fifun u, ti a o si sán a
pada fun u ẹ̀wẹ?
36 Nitori lati ọdọ rẹ̀, nipa rẹ̀, ati fun u
li ohun gbogbo: ẹniti ogo wà fun lailai.
Amin.

## ORI 12.

NITORINA mo fi iyọ́nu Ọlọrun bẹ̀ nyin,
ará, ki ẹnyin ki o le fi ara nyin ru
ẹbọ ãye, mimọ́, itẹwọgbà fun Ọlọrun, eyini
ni iṣe sisin nyin ti o jana.
2 Ki ẹ má si da ara nyin pọ̀ mọ́ aiye yi:
ṣugbọn ki ẹ parada lati di titun ninu nyin,
ki ẹnyin ki o le ri idi ifẹ Ọlọrun, ti o'dara,
ti iṣe itẹwọgbà, ti o si pé.
3 Njẹ mo wi fun olukuluku enia ti o wà
ninu nyin, nipa ore-ọfẹ ti a fifun mi, ki o
máṣe rò jù bi o ti yẹ ni rirò lọ; ṣugbọn ki
o le rò niwọntunwọnsin, bi Ọlọrun ti fi ìwọn
igbagbọ́ fun olukuluku.
4 Nitori gẹgẹ bi awa ti li ẹ̀ya pipọ li
ara kan, ti gbogbo ẹ̀ya kò si ni iṣẹ kanna:
5 Bẹ̃li awa, pipọ, a jẹ ara kan lara
Kristi, ati olukuluku ẹ̀ya ara ọmọnikeji rẹ̀.
6 Njẹ bi awa si ti nri ọ̀tọ-ọ̀tọ ẹ̀bun gbà
bi ore-ọfẹ ti a fifun wa, bi o ṣe isọtẹlẹ ni, jẹ
ki a mã sọtẹlẹ ni ìwọn igbagbọ́;
7 Tabi iṣẹ iranṣẹ, ki a mã kọjusi iṣẹ
iranṣẹ wa: tabi ẹniti nkọ́ni, ki o kọjusi
kíkọ;
8 Tabi ẹniti o ngbàni niyanju, si igbi-
yanju: ẹniti o nfi funni ki o mã fi inu kan
ṣe e; ẹniti nṣe olori, ki o mã ṣe e li oju
mejeji; ẹniti nṣãnu, ki o mã fi inù didùn
ṣe e.
9 Ki ifẹ ki o wà li aiṣẹtan. Ẹ takéte si
ohun ti o ṣe buburu; ẹ fi ara mọ́ ohun ti o
ṣe rere.
10 Ẹ mã fi inu rere fẹ ara nyin ni ifẹ
ará: ni ti ọlá, ẹ mã fi iyìn fun ọmọnikeji
nyin;
11 Ẹ máṣe imẹlẹ ni iṣẹ iṣe; ni igbona
ọkàn; ẹ mã sìn Oluwa;
12 Ẹ mã yọ̀ ni ireti; ẹ mã mu sũru
ninu ipọnju; ẹ mã duro gangan si adura
igbà;
13 Ẹ mã pín fun aini awọn enia mimọ́;
fi ara nyin fun alejò iṣe.
14 Ẹ mã sure fun awọn ti nṣe inunibini
si nyin: ẹ mã sure, ẹ má si ṣẹpè.
15 Awọn ti nyọ̀, ẹ mã ba wọn yọ̀, awọn
ti nsọkun, ẹ ma ba wọn sọkun.
16 Ki ẹnyin ki o wà ni inu kanna si ara
nyin. Ẹ máṣe tọju ohun giga, ṣugbọn ki
ohun ti kò niyìn ki o kún nyin loju. Ẹ
máṣe ọlọ́gbọn li oju ara nyin.
17 Ẹ máṣe fi buburu gbẹsan buburu fun
ẹnikẹni. Ẹ mã pèse ohun ti o tọ́ li oju
enia gbogbo.

Digitized by Google

18 Bi o le ṣe, bi o ti wà ni ipá nyin, ẹ
mã fi alafia ba gbogbo enia gbé.
19 Olufẹ ọwọn, ẹ máṣe gbẹsan fun ara
nyin, ṣugbọn ẹ fi àye silẹ fun ibinu ; ni-
tori a kọ ọ pe, Oluwa wipe, Ẹsan ni ti emi ;
emi o gbẹsan.
20 Nitorina bi ebi ba npa ọtá rẹ, fun u
li onjẹ ; bi ongbẹ ba ngbẹ ẹ, fun u li ohun
mimu : ni ṣiṣe bẽ iwọ o kó oguna jọ si i li
ori.
21 Ki a má fi buburu ṣẹgun rẹ, ṣugbọn fi
rere ṣẹgun buburu.

ORI 13.

KI olukuluku ọkàn ki o foribalẹ fun
agbara ti o jù u. Nitori kò si agbara
kan, bikoṣe lati ọdọ Ọlọrun wá : gbogbo
agbara ti o wà lati ọdọ Ọlọrun li a ti làna
rẹ wá.
2 Njẹ ẹniti o ba tapá si agbara, o tapá
si ìlana Ọlọrun : awọn ẹniti o ba si ntapá,
nwọn o gbà ẹbi fun ara wọn.
3 Nitori awọn ijoye kì iṣe ẹ̀ru si iṣẹ rere,
bikoṣe si iṣẹ buburu. Njẹ iwọ kì yio ha
bẹ̀ru agbara? ṣe eyi ti o dara, iwọ o si gbà
iyìn lọdọ rẹ na :
4 Nitori iranṣẹ Ọlọrun ni iṣe si ọ fun
rere. Ṣugbọn bi iwọ ba ṣe buburu, mã
bẹru ; nitori kò rù idà oyè na lasan : ni-
tori iranṣẹ Ọlọrun ni iṣe, olugbẹsan lati
ṣiṣẹ ibinu si ara awọn ẹniti nṣe buburu.
5 Nitorina ẹnyin kò gbọdọ ṣaima tẹriba,
kì iṣe nitori ti ibinu nikan, ṣugbọn nitori
ìmọ-ninu pẹlu.
6 Nitori eyi na ẹ mã san owo-ode pẹlu :
nitori iranṣẹ Ọlọrun ni nwọn, eyiyi na ni
nwọn mbojuto nigbagbogbo.
7 Njẹ ẹ san gbese fun ẹni gbogbo : owo-
ode fun ẹniti owo-ode iṣe tirẹ̀ : owo-bode
fun ẹniti owo-bode iṣe tirẹ̀ ; ẹ̀ru fun ẹniti
ẹ̀ru iṣe tirẹ̀ ; ọlá fun ẹniti ọlá iṣe tirẹ̀.
8 Ẹ máṣe jẹ ẹnikẹni ni gbese ohun kan,
bikoṣepe ki a fẹ ọmọnikeji ẹni : nitori
ẹniti o ba fẹ ọmọnikeji rẹ̀, o kó ofin ja.
9 Nitori eyiyi, Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga,
Iwọ kò gbọdọ pania, Iwọ kò gbọdọ jale,
Iwọ kò gbọdọ jẹri eke, Iwọ kò gbọdọ ṣoju-
kòkoro ; bi ofin miran ba si wà, li aifà a
gùn lọ titi o wà ninu ọ̀rọ yi pe, Iwọ fẹ
ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ.
10 Ifẹ kì iṣe ohun buburu si ọmọ-nikeji
rẹ̀ ; nitorina ifẹ li akója ofin.
11 Ati eyiyi, ti a nmọ̀ akokò pe, o to
wakati ati jí loju orun : nitori nisisiyi ni
igbala wa sunmọ etile jù igbati awa ti gba-
gbọ́ lọ.
12 Oru bukọja tan, ọsán kù si dẹ̀dẹ : ni-
torina ẹ jẹ ki a bọ́ ara iṣẹ òkunkun silẹ, ki
a si di ihamọra imọlẹ.
13 Jẹ ki a mã rìn ìrin titọ, bi li ọsán ;
kì iṣe ni iréde-oru ati ni imọti-para, kì iṣe
li asùn má dide ni yẹ̀wu ati aiye jijẹ, kì iṣe
ni ìja ati ilara.
14 Ṣugbọn ẹ mu Jesu Kristi Oluwa wọ̀,
ki ẹ má si pèse fun ara, lati ṣe ifẹkufẹ rẹ̀.

ORI 14.

ẸNITI o ba ṣe ailera ni igbagbọ́ on ni ki
ẹ gbà si ọdọ, li aitọ́-pinpin iṣiyemeji
rẹ̀.
2 Ẹnikan gbagbọ́ pe on le ma jẹ ohun
gbogbo : ẹlomiran, ti o si ṣe alailera ni
igbagbọ́, o njẹ ewebẹ.
3 Ki ẹniti njẹ ki máṣe kẹgan ẹniti kò jẹ;
ki ẹniti kò si jẹ ki o máṣe ba ẹniti njẹ
wijọ : nitori Ọlọrun ti gbà a.
4 Iwọ tani mba ọmọ-ọdọ ẹnikeji rẹ̀ wijọ?
oluwa tirẹ̀ li o duro fun, tabi on li o si ṣubu
fun. Bẹ̃ni, a o si gbé e duro : nitori Ọlọ-
run si le mu u duro.
5 Ẹnikan mbuyìn fun ọjọ kan jù omiran
lọ : ẹnikeji mbuyìn fun ọjọ gbogbo bakan-
na. Ki olukuluku ki o sá da ara rẹ̀ loju
ninu ara rẹ̀.
6 Ẹniti o ba nkiyesi ọjọ, o nkiyesi ọjọ
fun Oluwa ; ẹniti kò ba si kiyesi ọjọ, fun
Oluwa ni kò kiyesi i. Ẹniti njẹ, o njẹ fun
Oluwa, nitori o dupẹ lọwọ Ọlọrun ; ẹniti
kò si jẹ, fun Oluwa ni kò si jẹ, o si dupẹ
lọwọ Ọlọrun.
7 Nitori kò si ẹnikan ninu wa ti o wà
lãye fun ara rẹ̀, kò si si ẹniti o nkú fun ara
rẹ̀.
8 Nitori bi awa ba wà lãye, awa wà lãye
fun Oluwa ; bi awa ba si kú, awa kú fun
Oluwa : njẹ bi awa wà lãye, tabi bi awa kú
ni, ti Oluwa li awa iṣe.
9 Nitori idi eyi na ni Kristi ṣe kú, ti o
si jinde, ti o si tún yè, ki o le ṣe Oluwa ati
okú ati alãye.
10 Ṣugbọn ẽhatiṣe ti iwọ fi mba arakọn-
rin rẹ wijọ? tabi ẽsitiṣe ti iwọ fi nkẹgan
arakọnrin rẹ? gbogbo wa ni yio sá duro
niwaju itẹ́ idajọ Kristi.
11 A sá kọ ọ pe, Oluwa wipe, Bi emi ti
mbẹ lãye, gbogbo ẽkún ni yio kunlẹ fun
mi, ati gbogbo ahọn ni yio si jẹwọ fun
Ọlọrun.
12 Njẹ bẽ olukuluku wa ni yio rò ti ara
rẹ̀ fun Ọlọrun.
13 Nitorina ẹ má tún jẹ ki a ma da ara
wa lẹjọ mọ́ : ṣugbọn ẹ kuku ṣe ẹjọ eyi, ki

Digitized by Google

ẹnikẹni ki o má fi ohun idùgbolu tabi ohun ikọsẹ̀ si ọ̀na arakọnrin rẹ̀.

14 Emi mọ̀, emi si gbagbọ́ nipa ti Jesu Oluwa pe, kò si ohun ti o ṣe aimọ́ funrarẹ̀: ṣugbọn fun ẹniti o ba kà ohunkohun si aimọ́, on li o ṣe aimọ́ fun.

15 Ṣugbọn bi inu arakọnrin rẹ kò ba dùn si onjẹ rẹ, njẹ iwọ kò fi ifẹni rìn mọ́. Ẹniti Kristi kú fun máṣe fi onjẹ rẹ pa a rúgbe.

16 Njẹ ẹ máṣe jẹ ki a ma sọrọ buburu si ore nyin.

17 Nitori ijọba Ọlọrun kì iṣe jijẹ ati mimu; bikoṣe ododo, ati alafia, ati ayọ̀ nipa ti Ẹmí Mimọ́.

18 Nitori ẹniti o ba nsìn Kristi ninu nkan wọnyi, on li Ọlọrun itẹwọgbà, on li enia si ifi iyìn fun.

19 Njẹ ki awa ki o mã lepa ohun ti iṣe ti alafia, ati ohun ti awa o le fi mu ara wa duro.

20 Nitori onjẹ, máṣe bà iṣẹ Ọlọrun jẹ. Ohun gbogbo li o mọ́ nitõtọ; ṣugbọn buburu ni fun oluwarẹ̀ ti o nfi ẹ̀ṣẹ jẹ.

21 O yẹ ki a má tilẹ jẹ ẹran, ki a má mu ọti-waini, ati ohun kan nipa eyi ti arakọnrin rẹ dugbolu, ti a o si fi mu u kọsẹ̀ ati ti a o si fi sọ ọ di alailera.

22 Iwọ ni igbagbọ́? ni i fun ara rẹ niwaju Ọlọrun. Ayọ̀ ni fun oluwarẹ̀ ti kò dẹbi fun ara rẹ̀ li ohun ti o yàn.

23 Ẹniti o ba si nfi iyemeji jẹ, o jẹbi bi o ba jẹ, nitoriti kò fi igbagbọ́ jẹ: ati ohunkohun ti kò ba ṣe ti igbagbọ́, ẹ̀ṣẹ ni.

## ORI 15.

NJẸ awa ti o lera ni iba ma rẹrù ailera awọn alailera, ki a máṣe ohun ti o wù ara wa.

2 Ki olukuluku wa ki o mã ṣe ohun ti o wù ọmọnikeji rẹ̀ si rere rẹ̀ lati mu u duro.

3 Nitori Kristi kò ṣe ohun ti o wù ara rẹ̀; ṣugbọn bi a ti kọ ọ pe, Ẹgan awọn ti ngàn ọ bọ́ lù mi.

4 Nitori ohunkohun ti a ti kọ tẹlẹ, a ti kọ ọ fun kíkọ wa, nipa sũru ati itunu iwe mimọ́ ki awa le ni ireti.

5 Njẹ ki Ọlọrun sũru ati itunu ki o fifun nyin lati mã ṣe inu kan si ara nyin gẹgẹ bi Kristi Jesu:

6 Ki ẹnyin ki o le fi ọkàn ati ẹnu kan yìn Ọlọrun, Baba Jesu Kristi Oluwa logo.

7 Nitorina ẹ gbá ara nyin mọra, gẹgẹ bi Kristi ti gbá wa mọra fun ogo Ọlọrun.

8 Mo si wipe, Jesu Kristi li o ṣe iranṣẹ ikọla nitori otitọ Ọlọrun, lati mu awọn ileri na duro ti a ti ṣe fun awọn baba:

9 Ati ki awọn Keferi ki o le yìn Ọlọrun logo nitori ãnu rẹ̀; gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Nitori eyi li emi o jẹwọ fun ọ lãrin awọn Keferi, emi o si kọrin si orukọ rẹ.

10 O si tún wipe, Ẹnyin Keferi, ẹ mã yọ̀ pẹlu awọn enia rẹ̀.

11 Ati pẹlu, Ẹnyin Keferi gbogbo, ẹ yìn Oluwa; ẹ si kokikí rẹ̀, ẹnyin enia gbogbo.

12 Isaiah si tún wipe, Gbòngbo Jesse kan mbọ̀ wá, ati ẹniti yio dide jọba lori awọn Keferi; on li awọn Keferi yio gbẹkẹle.

13 Njẹ ki Ọlọrun ireti ki o fi gbogbo ayọ̀ on alafia kún u fun nyin ni igbagbọ́, ki ẹnyin ki o le pọ̀ ni ireti nipa agbara Ẹmí Mimọ́.

14 Ará mi, emi tikarami si mọ̀ ninu ara mi nipa ti nyin pe, ẹnyin si kun fun ore, a si fi gbogbo imọran kún u fun nyin, ẹnyin si le ma kìlọ fun ara nyin.

15 Ṣugbọn, ará mi, mo fi igboju kọwe si nyin li apakan, bi ẹni rán nyin leti, nitori ore-ọfẹ ti a ti fifun mi lati ọdọ Ọlọrun wá,

16 Ki emi ki o le ṣe alufa Jesu Kristi si awọn Keferi, lati ta ọrẹ ihin-rere Ọlọrun, ki ọrẹ awọn Keferi ki o le di itẹwọgbà, ti a sọ di mimọ́ nipa Ẹmí Mimọ́.

17 Mo si ni ibi ti emi le ṣogo nipa Jesu Kristi li ohun ti iṣe ti Ọlọrun.

18 Emi kò sá gbọdọ sọ ohun kan ninu eyi ti Kristi kò ti ọwọ́ mi ṣe, lati mu awọn Keferi gbagbọ́, nipa ọ̀rọ ati iṣe.

19 Nipa ti àmi ati iṣẹ iyanu nla, nipa agbara Ẹmí Ọlọrun; tobẹ̃ lati Jerusalemu yiká kiri titi o fi de Illirikoni, mo si ti wasu ihin-rere Kristi ni kikun.

20 Pẹlupẹlu tobẹ̃ ni mo lakaka lati wasu ihin-rere na, kì iṣe nibiti a gbé ti da orukọ Kristi ri, ki emi ki o máṣe mọ amọle si ipilẹṣẹ ẹlomiran.

21 Ṣugbọn bi a ti kọ ọ pe, Awọn ẹni ti a kò ti sọrọ rẹ̀ fun, nwọn o ri i: ati fun awọn ti kò ti gbọ́, oyé yio yé wọn.

22 Nitorina pẹlu li àye ṣe há gágá fun mi lati tọ̀ nyin wá.

23 Ṣugbọn nisisiyi bi emi kò ti li àye mọ́ li ẹkùn wọnyi, bi emi si ti ngbé e wò lati tọ̀ nyin wá lati ọdún melo wọnyi;

24 Nigbakugba ti mo ba mu ọ̀na àjo mi pọn lọ si Spania, emi o tọ̀ nyin wá: nitori emi gbẹkẹle pe emi o ri nyin li ọ̀na àjo mi, ati lati mu mi já ọ̀na mi nibẹ̀ lati ọdọ nyin lọ, bi mo ba tète kún fun ẹgbẹ nyin li apakan.

25 Ṣugbọn nisisiyi emi nlọ si Jerusalemu lati ṣe iranṣẹ fun awọn enia mimọ́.

Digitized by Google

26 Nitoriti o wù awọn ará Makedonia ati Akaia lati da owo kan jọ fun awọn talakà enia mimọ́ ti o wà ni Jerusalemu.

27 Nitõtọ, ifẹ inu rere wọn ni; ojigbese wọn ni nwọn sá ṣe. Nitori bi o ba ṣepe a fi awọn Keferi ṣe alajọni ninu ohun ẹmí wọn, iṣẹ wọn si ni lati fi nkan ti ara ta wọn lọrẹ.

28 Njẹ nigbati mo ba ṣe eyi tan, ti mo ba si dí èdidi eso yi fun wọn tan, emi o ti ọdọ nyin wá si Spania.

29 O si da mi loju pe, nigbati mo ba de ọdọ nyin, emi o wá ni kíkún ibukun ihinrere Kristi.

30 Mo si bẹ̀ nyin ará, nitori Jesu Kristi Oluwa, ati itori ifẹ Ẹmí, ki ẹnyin ki o ba mi gbiyanju ninu adura nyin si Ọlọrun fun mi;

31 Ki a le gbà mi lọwọ awọn alaigbagbọ́ ni Judea; ki iṣẹ ti mo ni si Jerusalemu ki o le di itẹwọgbà lọdọ awọn enia mimọ́;

32 Ki emi ki o le fi ayọ̀ tọ̀ nyin wá nipa ifẹ Ọlọrun, ki inu mi ki o le tutù pọ̀ pẹlu nyin.

33 Njẹ ki Ọlọrun alafia ki o wà pẹlu gbogbo nyin. Amin.

## ORI 16.

MO yìn Febe, arabirin wa si nyin, ẹniti iṣe iranṣẹ ijọ ti o wà ni Kenkrea:

2 Ki ẹnyin ki o gbà a niti Oluwa, bi o ti yẹ fun awọn enia mimọ́, ki ẹnyin ki o si ràn a lọwọ iṣẹkiṣẹ ti o nwá ni iranlọwọ lọdọ nyin: nitoriti o ti nṣe oluranlọwọ awọn enia pipọ, ati ti emi tikarami pẹlu.

3 Ẹ kí Priskilla ati Akuila, awọn alabaṣe mi ninu Kristi Jesu:

4 Awọn ẹniti o ti itori ẹmí mi, fi ọrùn wọn lelẹ: kìki awọn ẹniti mo dupẹ fun nikan kọ́, ṣugbọn gbogbo ijọ larin awọn Keferi pẹlu.

5 Ẹ si kí ijọ ti o wà ni ile wọn. Kí Epenetu, olufẹ mi ọwọn, ẹniti iṣe akọso Akaia fun Kristi.

6 Ẹ kí Maria, ti o ṣe iṣẹ pipọ fun wa.

7 Ẹ kí Androniku ati Junia, awọn ibatan mi, ati awọn ẹgbẹ mi ninu tubu, awọn ẹniti o ni iyìn lọdọ awọn Aposteli, awọn ẹniti o ti wà ninu Kristi ṣaju mi pẹlu.

8 Ẹ kí Amplia olufẹ mi ninu Oluwa.

9 Ẹ kí Urbani, oluranlọwọ wa ninu Kristi, ati Staki olufẹ mi.

10 Ẹ kí Apelle ẹniti a mọ̀ daju ninu Kristi. Ẹ kí awọn arale Aristobulu.

11 Ẹ kí Herodioni, ibatan mi. Ẹ kí awọn arale Narkissu, ti o wà ninu Oluwa.

12 Ẹ kí Trifena ati Trifosa, ti nṣiṣẹ ninu Oluwa. Ẹ kí Persi olufẹ, ti o ṣiṣẹ pipọ ninu Oluwa.

13 Ẹ kí Rufu ti a yàn ninu Oluwa, ati iya rẹ̀ ati ti emi.

14 Ẹ kí Asinkritu, Flegoni, Herma, Patroba, Herme, ati awọn arakọnrin ti o wà pẹlu wọn.

15 Ẹ kí Filologu, ati Julia, Nereu, ati arabirin rẹ̀, ati Olimpa, ati gbogbo awọn enia mimọ́ ti o wà pẹlu wọn.

16 Ẹ fi ifẹnukonu mimọ́ kí ara nyin. Gbogbo ijọ Kristi kí nyin.

17 Ará, emi si bẹ̀ nyin, ẹ mã kiyesi awọn ti nṣe ìyapa, ati awọn ti nmu ohun ikọsẹ̀ wá lodi si ẹkọ́ wa ti ẹnyin kọ́; ẹ si kuro ni isọ wọn.

18 Nitori awọn ti o ri bẹ̃ kò sìn Jesu Kristi Oluwa wa, bikoṣe ikùn ara wọn; ọ̀rọ rere ati ọrọ didùndidùn ni nwọn fi npa awọn ti kò mọ̀ meji li ọkàn dà.

19 Nitori igbagbọ́ nyin tàn kalẹ de ibigbogbo. Mo si yọ̀ nitori ti nyin: ṣugbọn sibẹ emi nfẹ ki oyé ki o yé nyin si ohun ti o ṣe rere, ki ẹ si ṣe òpe si ohun ti iṣe buburu.

20 Ọlọrun alafia yio si tẹ̀ Satani mọlẹ li atẹlẹsẹ nyin nisisiyi. Ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa ki o wà pẹlu nyin. Amin.

21 Timoteu, alabaṣe mi, ati Lukiu, ati Jasoni, ati Sosipateru, awọn ibatan mi kí nyin.

22 Emi Tertiu ti nkọ Episteli yi, kí nyin ninu Oluwa.

23 Gaiu, bãle mi, ati ti gbogbo awọn enia Ọlọrun, kí nyin. Erastu, olutọju iṣura ilu, kí nyin, ati Kuartu arakọnrin.

24 Ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ki o wà pẹlu gbogbo nyin. Amin.

25 Njẹ fun ẹniti o li agbara lati mu nyin duro, bi ihin-rere mi ati iwasu Jesu Kristi, nipa ifihan ohun ijinlẹ, ti a ti pamọ́ lati igba ọjọ ìwa,

26 Ti a si nfihàn nisisiyi, ati nipa iwemimọ́ awọn woli, gẹgẹ bi ofin Ọlọrun ainipẹkun, ti a nfihàn fun gbogbo orilẹ-ède si igbọràn igbagbọ́:

27 Ọlọrun ọlọ́gbọn nikanṣoṣo li ogo wà fun, nipasẹ Jesu Kristi lailai. Amin.

---

A kọ ọ si awọn ara Romu lati Korinti lọ, a si ranṣẹ rẹ̀ lati ọwọ́ Febe iranṣẹ ijọ ti o wà ni Kenkrea.

Digitized by Google

EPISTELI IKINI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA KORINTI.

## ORI 1.

PAULU, ẹniti a pè ṣe Aposteli Jesu Kristi
nipa ifẹ Ọlọrun, ati Sostene arakọnrin,
2 Si ijọ enia Ọlọrun ti o wà ni Korinti,
si awọn ti a sọdi mimọ́ ninu Kristi Jesu,
ẹniti a npè li enia mimọ́ pẹlu gbogbo awọn
ti npè orukọ Jesu Kristi Oluwa wa nibi
gbogbo, ti iṣe ti wọn ati ti wa:
3 Ore-ọfẹ si nyin, ati alafia, lati ọdọ
Ọlọrun Baba wa, ati Jesu Kristi Oluwa wa.
4 Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun mi nigbagbogbo
nitori nyin, nitori ore-ọfẹ Ọlọrun ti a fifun
nyin nipa Jesu Kristi;
5 Nitoripe nipasẹ rẹ̀ li a ti sọ nyin di
ọlọrọ̀ li ohun gbogbo, ninu ọ̀rọ-isọ gbogbo,
ati ninu ìmọ gbogbo;
6 Ani gẹgẹ bi a ti fi idi ẹrí Kristi kalẹ
ninu nyin:
7 Gẹgẹ bi ẹnyin kò ti rẹ̀hin ninu ẹ̀bun-
kẹbun; ti ẹnyin si nreti ifarahàn Jesu
Kristi Oluwa wa:
8 Ẹniti yio si fi idi nyin kalẹ titi de
opin pẹlu, ki ẹnyin ki o le jẹ alailẹgàn li
ọjọ Jesu Kristi Oluwa wa.
9 Olododo sá li Ọlọrun, nipasẹ ẹniti a ti
pè nyin si ìdapọ ti Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀
Oluwa wa.
10 Mo si bẹ̀ nyin, ará, li orukọ Jesu
Kristi Oluwa wa, ki gbogbo nyin mã sọ̀rọ
ohun kanna, ati pe ki ìyapa ki o máṣe si
ninu nyin; ṣugbọn ki a le ṣe nyin pé ni
inu kan, ati ni ìmọ kan.
11 Nitori a ti fihàn mi nipa ti nyin, ará
mi, lati ọdọ awọn ara ile Kloe, pe ìja mbẹ
larin nyin.
12 Eyi ni mo wi nisisiyi pe, olukuluku
nyin nwipe, Emi ni ti Paulu; ati emi ni
ti Apollo; ati emi ni ti Kefa; ati emi ni ti
Kristi.
13 Kristi ha yà si ara rẹ̀ bi? iṣe Paulu
li a kàn mọ agbelebu fun nyin bi? tabi li
orukọ Paulu li a baptisi nyin bi?
14 Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun ti emi kò bap-
tisi ẹnikẹni ninu nyin, bikoṣe Krispu ati
Gaiu;
15 Ki ẹnikẹni ki o máṣe wipe mo ti
mbaptisi li orukọ emi tikarami.
16 Mo si baptisi awọn ara ile Stefana
pẹlu: emi kò si mọ̀ bi mo ba baptisi awọn
ẹlomiran pẹlu.
17 Nitori Kristi kò rán mi lọ ibaptisi,
bikoṣe lati wãsu ihin-rere: kì iṣe nipa ọ̀rọ
ọgbọ́n, ki a máṣe sọ agbelebu Kristi di
ailagbara.
18 Nitoripe wère li ọ̀rọ agbelebu si awọn
ti o ṣegbé; ṣugbọn si awa ti a ngbalà,
agbara Ọlọrun ni.
19 Nitoriti a kọ ọ wipe, Emi o pa ọgbọ́n
awọn ọlọ́gbọn run, emi o si sọ oyé awọn
ọlọ́gbọn dasan.
20 Nibo li awọn ọlọ́gbọn na gbé wà?
nibo li awọn akọwe na gbé wà? nibo li
awọn ojiyan aiye yi na gbé wà? Ọlọrun
kò ha ti sọ ọgbọ́n aiye yi di wère?
21 Nitoripe ninu ọgbọ́n Ọlọrun lẹhin
igbati aiye kò mọ̀ Ọlọrun mọ́ nipa ọgbọ́n,
o wù Ọlọrun nipa wère iwasu lati gbà awọn
ti o gbagbọ́ là.
22 Nitoripe awọn Ju mbère àmi, awọn
Hellene a si ma ṣafẹri ọgbọ́n:
23 Ṣugbọn awa nwasu Kristi ti a kàn
mọ agbelebu, ohun ikọsẹ̀ fun awọn Ju, ati
ohun wère fun awọn Hellene;
24 Ṣugbọn fun awọn ti a pè, ati Ju ati
Hellene, Kristi li agbara Ọlọrun, ati ọgbọ́n
Ọlọrun.
25 Nitoripe wère Ọlọrun gbọ́n jù ọgbọ́n
enia lọ; ati ailera Ọlọrun li agbara jù
agbara enia lọ.
26 Nitoriti ẹnyin ri ìpe nyin, ará, bi o
ti ṣepe kì iṣe ọ̀pọ awọn ọlọ́gbọn enia nipa ti
ara, kì iṣe ọ̀pọ awọn alagbara, kì iṣe ọ̀pọ
awọn ọlọlá li a pè:
27 Ṣugbọn Ọlọrun ti yàn ohun wère
aiye lati fi dãmu awọn ọlọgbọ́n; Ọlọrun si
ti yàn ohun ailera aiye lati fi dãmu ohun
ti o li agbara;

Digitized by Google

28 Ati ohun ti kò niyìn li aiye, ati ohun
ti a nkẹgàn, li Ọlọrun si ti yàn, ani, ohun
ti kò si si, lati sọ ohun ti o wà dasan:
29 Ki o máṣe si ẹda ti yio ṣogo niwaju rẹ̀.
30 Ṣugbọn nipasẹ rẹ̀ li ẹnyin wà ninu
Kristi Jesu, ẹniti Ọlọrun fi ṣe ọgbọ́n, ati
ododo, ati isọdimimọ́, ati idande fun wa:
31 Gẹgẹ bi a ti kọ ọ, pe, Ẹniti o ba
nṣogo, ki o ma ṣogo ninu Oluwa.

## ORI 2.

ATI emi, ará, nigbati mo tọ̀ nyin wá, kì
iṣe ọ̀rọ didùndidùn tabi ti ọgbọ́n ni
mo fi tọ̀ nyin wá, nigbati emi nsọ̀rọ ẹri
Ọlọrun fun nyin.
2 Nitoriti mo ti pinnu rẹ̀ ninu mi pe,
emi kì yio mọ̀ ohunkohun ninu nyin,
bikoṣe Jesu Kristi, ẹniti a kàn mọ agbe-
lebu.
3 Emi si wà pẹlu nyin ni ailera, ati ni
ẹ̀ru, ati ni ọ̀pọlọpọ iwarìri.
4 Ati ọ̀rọ ati iwasu mi kì iṣe nipa ọ̀rọ
ọgbọ́n enia, ti a fi nyi ni lọkàn pada, biko-
ṣe nipa ifihan ti Ẹmí ati ti agbara:
5 Ki igbagbọ́ nyin ki o máṣe duro ninu
ọgbọ́n enia, bikoṣe ninu agbara Ọlọrun.
6 Ṣugbọn awa nsọ̀rọ ọgbọ́n larin awọn ti
o pé: ṣugbọn kì iṣe ọgbọ́n ti aiye yi, tabi
ti awọn ọmọ-alade aiye yi, ti o di asan:
7 Ṣugbọn awa nsọ̀rọ ọgbọ́n Ọlọrun ninu
ọ̀rọ ijinlẹ, ani ọgbọ́n ti o farasin, eyiti
Ọlọrun ti làna silẹ ṣaju ipilẹṣẹ aiye si ogo
wa:
8 Eyiti ẹnikẹni ninu awọn ọmọ-alade
aiye yi kò mọ̀: nitori ibaṣepe nwọn ti mọ̀
ọ, nwọn kì ba ti kàn Oluwa ogo mọ agbe-
lebu.
9 Ṣugbọn gẹgẹ bi a ti kọ ọ, pe, Oju kò
ti iri, etí kò ti igbọ́, bẹ̃ni kò si ti iwọ̀ àiya
enia lọ, ohun ti Ọlọrun ti pèse silẹ fun awọn
ti o fẹ ẹ.
10 Ṣugbọn Ọlọrun ti fi wọn hàn fun
awa nipa Ẹmí rẹ̀: nitoripe Ẹmí ni nwadi
ohun gbogbo, ani, ohun ijinlẹ ti Ọlọrun.
11 Nitoripe tali oluwarẹ̀ na ti o mọ̀
ohun enia kan, bikoṣe ẹmí enia ti o wà ni-
nu rẹ̀? bẹ̃ni kò si ẹnikan ti o mọ̀ ohun
Ọlọrun, bikoṣe Ẹmí Ọlọrun.
12 Ṣugbọn awa ti gbà, kì iṣe ẹmi ti aiye,
bikoṣe ẹmí ti iṣe ti Ọlọrun; ki awa ki o le
mọ̀ ohun ti a fifun wa li ọfẹ lati ọdọ Ọlọ-
run wá.
13 Ohun na ti awa si nsọ, kì iṣe ninu
ọ̀rọ ti ọgbọ́n enia nkọ́ni, ṣugbọn eyiti Ẹmí
Mimọ́ fi nkọ́ni; eyiti a nfi ohun ẹmí ṣapẹ-
rẹ ohun ẹmí.
14 Ṣugbọn enia nipa ti ara kò le gbà
ohun ti Ẹmí Ọlọrun wọnni: nitoripe wère
ni nwọn jasi fun u: bẹ̃li on kò si le mọ̀
wọn, nitori nipa ti ẹmi li a fi nmọ̀ wọn.
15 Ṣugbọn ẹniti o wà nipa ti ẹmí nwadi
ohun gbogbo, ṣugbọn kò si ẹnikẹni ti iwa-
di rẹ̀.
16 Nitoripe tali o mọ̀ inu Oluwa, ti yio
fi ma kọ́ ọ? Ṣugbọn awa ni inu Kristi.

## ORI 3.

ATI emi, ará, emi kò si le ba nyin sọ̀rọ bi
awọn ti iṣe ti ẹmí, bikoṣe bi awọn ti
iṣe ti ara, ani bi awọn ọmọ-ọwọ ninu
Kristi.
2 Emi ti fi wàra bọ́ nyin, kì iṣe onjẹ:
nitoripe titi di isisiyi, ẹnyin kò ti le gbà a,
bẹ̃ni kì iṣe nisisiyi na li ẹnyin le gbà a.
3 Nitori ẹnyin wà ni ti ara sibẹ: nitori
niwọn igbati ilara, ati ìja, ati ìyapa wà ni-
nu nyin, ẹnyin kò ha wà ni ti ara, ẹ kò si
nrìn gẹgẹ bi ti enia?
4 Nitoripe nigbati ẹnikan nwipe, Emi
ni ti Paulu; ati ekeji, Emi ni ti Apollo;
ẹnyin kò ha wà ni ti ara?
5 Njẹ tani Paulu, tani Apollo, bikoṣe
awọn iranṣẹ nipasẹ ẹniti ẹnyin ti gbagbọ́,
gẹgẹ bi Oluwa ti fun olukuluku enia?
6 Emi gbìn, Apollo bomirin; ṣugbọn
Ọlọrun ni nfi ibisi na funni.
7 Njẹ gẹgẹ bẹ̃ni kì iṣe ẹniti o gbìn
ohunkohun, bẹ̃ni kì iṣe ẹniti mbomirin;
bikoṣe Ọlọrun ti nfi ibisi funni.
8 Njẹ ẹniti ngbìn, ati ẹniti mbomirin,
ọkan li awọn mejeji jasi: olukuluku yio si
jẹ ère tirẹ̀ gẹgẹ bi iṣẹ on tikararẹ̀.
9 Nitoripe alagbaṣe pẹlu Ọlọrun li awa:
ẹnyin li ọgbà Ọlọrun, ẹnyin ni ile Ọlọrun.
10 Gẹgẹ bi ore-ọfẹ ti a fifun mi lati ọdọ
Ọlọrun wá, bi ọlọ́gbọn ọmọle, mo ti fi ipilẹ
sọlẹ, ẹlomiran si nmọle lori rẹ̀. Ṣugbọn ki
olukuluku kiyesara bi o ti nmọle lori rẹ̀.
11 Nitoripe kò si ipilẹ miran ti ẹnikan
le fi lelẹ jù eyiti a ti fi lelẹ lọ, ti iṣe Jesu
Kristi.
12 Njẹ bi ẹnikẹni ba kọle wura, fadaka,
okuta iyebiye, igi, koriko, akekù koriko
lori ipilẹ yi;
13 Iṣẹ olukuluku enia yio fi ara hàn;
nitoripe ọjọ nì yio fi i hàn, nitoripe nipa
iná li a o fi i hàn; iná yio si dán iṣẹ oluku-
luku wò irú eyiti iṣe.
14 Bi iṣẹ ẹnikẹni ti o ti ṣe lori rẹ̀ ba du-
ro, on o gbà ère.
15 Bi iṣẹ ẹnikẹni ba jóna, on o pàdanù:

Digitized by Google

şugbọn on tikararẹ̀ li a o gbalà ; şugbọn bi
ẹnipe nipa iná.
16 Ẹnyin kò mọ̀ pe tempili Ọlọrun li
ẹnyin iṣe, ati pe Ẹmí Ọlọrun mbẹ ninu
nyin ?
17 Bi ẹnikan ba pa tempili Ọlọrun run,
on ni Ọlọrun yio parun ; nitoripe mimọ́
ni tempili Ọlọrun, tempili ti ẹnyin iṣe.
18 Ki ẹnikẹni máṣe tàn ara rẹ̀ jẹ. Bi
ẹnikẹni ninu nyin ba dabi ẹnipe o gbọ́n li
aiye yi, ẹ jẹ ki o di aṣiwere, ki o le ba gbọ́n.
19 Nitori wère li ọgbọ́n ti aiye yi lọdọ
Ọlọrun. Nitoripe a ti kọ ọ pe, On mu
awọn ọlọgbọ́n nipa ọgbọ́n wọn.
20 O si tún wi ẹ̀wẹ pe, Oluwa mọ̀ ìronu
awọn ọlọgbọ́n pe, asan ni nwọn.
21 Nitorina ki ẹnikẹni máṣe ṣogo nipa
ti enia. Nitoripe ti nyin li ohun gbogbo ;
22 Iba ṣe Paulu, tabi Apollo, tabi Kefa,
tabi aiye, tabi ìye, tabi ikú, tabi ohun isisiyi,
tabi ohun igba ti mbọ̀ ; ti nyin ni
gbogbo wọn ;
23 Ẹnyin si ni ti Kristi ; Kristi si ni ti
Ọlọrun.

## ORI 4.

JẸ ki enia ki o ma kà wa bẽ bi iranṣẹ
Kristi, ati iriju awọn ohun ijinlẹ Ọlọrun.
2 Pẹlupẹlu a mbere lọwọ iriju pe ki
oluwarẹ̀ na ki o jẹ olõtọ.
3 Şugbọn bi o ṣe ti emi ni, ohun kikini
sá ni fun mi, ti ẹnikẹni yio fi ma wadi mi
lọdọ nyin, tabi lati mã ṣe idajọ mi nipa
idajọ enia : lõtọ emi kò ṣe idajọ emi tikarami.
4 Nitoriti emi kò mọ̀ ohunkohun si ara
mi : şugbọn nipa eyi na a kò dá mi lare :
şugbọn ẹniti nṣe idajọ mí li Oluwa.
5 Nitorina ẹ máṣe idajọ ohunkohun ṣaju
akokò na, titi Oluwa fi de, ẹniti yio mu
ohun òkunkun ti o farasin wá si imọlẹ, ti
yio si fi ìmọ ọkàn hàn pẹlu : nigbana li
olukuluku yio si ni iyìn tirẹ̀ lọdọ Ọlọrun.
6 Ará, nkan wọnyi ni mo ti fi nṣapẹrẹ si
emi tikarami ati Apollo nitori nyin ; ki
ẹnyin ki o le kọ́ nipa wa ki ẹ máṣe rò si
enia jù bi eyiti a kọwe rẹ̀ lọ, ki ẹnikan ki
o máṣe gbéraga ninu ara rẹ̀ nitori ẹnikan si
ẹnikeji.
7 Nitoripe tali o ha mu ọ yàtọ ? tabi
kili ohun ti iwọ ni ti iwọ kò ti gbà ? njẹ bi
iwọ ba ti gbà a, ẽhatiṣe ti iwọ fi nhalẹ, bi
ẹnipe gbigbà kọ́ iwọ gbà a ?
8 A sá tẹ́ nyin lọrùn nisisiyi, a sá ti sọ
nyin di ọlọrọ̀ nisisiyi, ẹnyin ti njọba lẹhin
wa : emi si nfẹ ki ẹnyin ki o jọba, ki awa
ki o le jùmọ jọba pẹlu nyin.
9 Nitori mo rò pe Ọlọrun ti fi awa
Aposteli kẹhin, bi ẹniti a yàn si ikú : nitoriti
a fi wa ṣe ẹni wiwò fun aiye, ati fun
awọn angeli, ati fun enia.
10 Awa sá jasi aṣiwere nitori Kristi,
şugbọn ẹnyin jasi ọlọgbọ́n ninu Kristi ;
awa jasi alailera, şugbọn ẹnyin di alagbara ;
ẹnyin di ọlọlá, şugbọn awa di ẹni ẹ̀gan.
11 Ani titi fi di wakati yi li ebi npa wa,
ti òrungbẹ si ngbẹ wa, awa si wà ni ìhoho,
a si nlù wa, awa kò si ni ibugbé kan ;
12 Awa nṣe lãlã, a si nfi ọwọ́ ara wa
ṣiṣẹ : nwọn ngàn wa, awa nsure ; nwọn
nṣe inunibini si wa, awa nforitì i :
13 Nwọn nkẹgàn wa, awa mbẹ̀bẹ ; a si
sọ wa dabi ohun ẽri aiye, bi idarọ ohun
gbogbo titi di oni-oloni.
14 Emi kò kọwe nkan wọnyi lati fi dojutì
nyin, şugbọn bi awọn ayanfẹ ọmọ mi,
mo kìlọ fun nyin.
15 Nitori bi ẹnyin tilẹ li ẹgbarun olukọni
ninu Kristi, şugbọn ẹnyin kò ni baba
pipọ : nitoripe ninu Kristi Jesu ni mo ti fi
ihin-rere bí nyin.
16 Nitorina ni mo bẹ̀ nyin, ẹ mã ṣe ọmọ
lẹhin mi.
17 Nitorina ni mo ṣe rán Timoteu si
nyin, ẹniti iṣe ọmọ mi olufẹ, ati olododo
ninu Oluwa, ẹniti yio ma mu nyin ranti
ọ̀na mi ti o wà niti Kristi, gẹgẹ bi mo ti
nkọ́ni ninu gbogbo ijọ nibigbogbo.
18 Njẹ awọn ẹlomiran fẹ̀ soke ninu nyin,
bi ẹnipe emi kì yio tọ̀ nyin wá mọ́.
19 Şugbọn emi o tọ̀ nyin wá ni lọ̃lọ̃ yi,
bi Oluwa ba fẹ, emi o si mọ̀, kì iṣe ọ̀rọ
awọn ẹniti nfẹ̀ soke, bikoṣe agbara wọn.
20 Nitori ijọba Ọlọrun kì iṣe ninu ọ̀rọ,
bikoṣe ninu agbara.
21 Kili ẹnyin nfẹ ? emi o ha tọ̀ nyin wá
ti emi ti kùmọ bi, tabi ni ifẹ, ati ẹmí
inututù ?

## ORI 5.

ANRÒHIN rẹ̀ kalẹ gbogbo pe, àgbere wà
ninu nyin, ati irú àgbere ti a kò ti
igburo rẹ̀ ninu awọn Keferi, pe ẹnikan ninu
nyin fẹ aya baba rẹ̀.
2 Ẹnyin si nfẹ̀ soke, ẹnyin kò kuku
binujẹ ki a le mu ẹniti o ṣe nkan yi kuro
larin nyin.
3 Nitoripe lõtọ, bi emi kò ti si lọdọ
nyin nipa ti ara, şugbọn ti mo wà nipa ti
ẹmí, emi ti pinnu rẹ̀ tan gẹgẹ bi ẹnipe mo
wà, nitori oluwarẹ̀ na ti o ṣe nkan bayi,

Digitized by Google

4 Li orukọ Jesu Kristi Oluwa wa, ni-
gbati ẹnyin ba kó ara nyin jọ, ati ẹmí mi,
pẹlu agbara Jesu Kristi Oluwa wa,
5 Lati fi irú enia bẽ fun Satani fun
iparun ara, ki a le gbà ẹmí là li ọjọ Jesu
Oluwa.
6 Iṣeféfe nyin kò dara. Ẹnyin kò mọ̀
pe iwukara diẹ ni imu gbogbo iyẹfun di
wiwu?
7 Nitorina ẹ mu iwukara atijọ kuro ninu
nyin, ki ẹnyin ki o le jẹ́ iyẹfun titun, bi
ẹnyin ti jẹ́ aiwukara. Nitori a ti kàn
Kristi irekọja wa mọ agbelebu fun wa:
8 Nitorina ẹ jẹ ki a ṣe ajọ na, kì iṣe pẹlu
iwukara atijọ, bẽni kì iṣe pẹlu iwukara
arankàn ati iwa buburu; bikoṣe pẹlu aiwu-
kara inu funfun ati otitọ.
9 Emi ti kọwe si nyin ninu iwe kan pe,
ki ẹ máṣe ba awọn àgbere kẹgbẹ pọ̀:
10 Ṣugbọn kì iṣe pẹlu awọn àgbere aiye
yi patapata, tabi pẹlu awọn olojukòkoro,
tabi awọn alọnilọwọgbà, tabi awọn abọ-
riṣa; njẹ ẹnyin kò le ṣaima ti aiye kuro.
11 Ṣugbọn mo kọwe si nyin nisisiyi pe,
ki ẹ máṣe ba oluwarẹ̀ kẹgbẹ, bi ẹnikẹni ti
a npè li ará ba jẹ àgbere, tabi olojukòkoro,
tabi abọriṣa, tabi ẹlẹgàn, tabi ọmọtipara,
tabi alọnilọwọgbà; ki ẹnyin ki o máṣe ba
irú enia bẽ jẹun pọ̀.
12 Nitori kili o jasi fun mi lati mã ṣe
idajọ awọn ti mbẹ lode? ẹnyin kò nṣe
idajọ awọn ti o wà ninu?
13 Ṣugbọn awọn ti o wà lode li Ọlọrun
nṣe idajọ fun. Nitorina ẹ yọ enia buburu
na kuro larin ara nyin.

## ORI 6.

ẸNIKẸNI ninu nyin, ti o ni ẹjọ kan si
ẹnikeji rẹ̀, o gbọdọ lọ si ibi idajọ
niwaju awọn alaiṣõtọ, laijẹ pe niwaju awọn
enia mimọ́?
2 Ẹnyin kò mọ̀ pe awọn enia mimọ́ ni
yio ṣe idajọ aiye? Njẹ bi o ba ṣepe a o
tipasẹ nyin ṣe idajọ aiye, ẹnyin ha ṣe alaiyẹ
lati ṣe idajọ ọ̀ran kekere julọ?
3 Ẹnyin kò mọ̀ pe awa o ṣe idajọ awọn
angeli? melomelo li ohun ti iṣe ti aiye yi?
4 Njẹ bi ẹnyin ba ni ṣe idajọ ohun ti iṣe
ti aiye yi, awọn alailọlá julọ ninu ijọ ni
ijoko lati ṣe idajọ rẹ̀ bi?
5 Mo sọ ọ fun itiju nyin. O le ri bẽ, ti
kò si ọlọgbọn kan ninu nyin? ani kò si
ẹniti iba le ṣe idajọ larin awọn arakọnrin
rẹ̀?
6 Ṣugbọn arakọnrin mba arakọnrin lọ si
ibi idajọ, ati eyini niwaju awọn alaigbagbọ́.
7 Njẹ ẹbi wà fun nyin patapata nisisiyi,
nitoriti ẹnyin mba ẹnikeji nyin lọ si ibi
idajọ. Eṣe ti ẹnyin kò kuku gbà ẹbi fun
ara nyin? ẽṣe ti ẹnyin kò kuku jẹ ki a rẹ́
ẹnyin tikara nyin jẹ?
8 Ndao ṣugbọn ẹnyin nṣe buburu, ẹ sì
rẹ́ ni jẹ, ati eyini awọn arakọnrin nyin.
9 Ẹnyin kò mọ̀ pe awọn alaiṣõtọ kì yio
jogún ijọba Ọlọrun? Ki a má tàn nyin
jẹ: kì iṣe awọn àgbere, tabi awọn abọriṣa,
tabi awọn panṣaga, tabi awọn alailera ọkàn,
tabi awọn ti nfi ọkọnrin bà ara wọn jẹ,
10 Tabi awọn olè, tabi awọn olojukò-
koro, tabi awọn ọmọtipara, tabi awọn
ẹlẹgàn, tabi awọn alọnilọwọgbà ni yio
jogún ijọba Ọlọrun.
11 Gẹgẹ bẽ si li awọn ẹlọmiran ninu
nyin ri: ṣugbọn a ti wẹ̀ nyin nù, ṣugbọn a
ti sọ nyin di mimọ́, ṣugbọn a ti da nyin
lare li orukọ Jesu Oluwa, ati nipa Ẹmí
Ọlọrun wa.
12 Ohun gbogbo yẹ fun mi, ṣugbọn
ohun gbogbo kò li ère: ohun gbogbo yẹ
fun mi, ṣugbọn emi kì yio jẹ ki a fi mi
sabẹ agbara ohunkohun.
13 Onjẹ fun inu, ati inu fun onjẹ: ṣu-
gbọn Ọlọrun yio pa ati on ati awọn mejeji
run. Nitori ara kì iṣe ti àgbere, bikoṣe ti
Oluwa; ati Oluwa si ni ti ara.
14 Ọlọrun ti o ti jí Oluwa na dide, yio
si jí wa dide pẹlu nipa agbara on tikararẹ̀.
15 Ẹnyin kò mọ̀ pe ẹ̀ya ara Kristi li ara
nyin? emi o ha mu ẹ̀ya ara Kristi, ki emi
ki o si fi ṣe ẹ̀ya ti àgbere bi? ki a má ri i.
16 Kinla? ẹnyin kò mọ̀ pe ẹniti o ba
dàpọ mọ́ àgbere kan di ara kan? nitoriti
o wipe, Awọn meji ni yio jẹ ara kan.
17 Ṣugbọn ẹniti a dàpọ mọ́ Oluwa di
ẹmí kan.
18 Ẹ mã sá fun àgbere. Gbogbo ẹ̀ṣẹ ti
enia ndá o wà lode ara rẹ̀; ṣugbọn ẹniti o
ṣe àgbere ṣẹ̀ si ara on tikararẹ̀.
19 Kinla? ẹnyin kò mọ̀ pe ara nyin ni
tempili Ẹmí Mimọ́, ti mbẹ ninu nyin, ti
ẹnyin ti gbà lọwọ Ọlọrun, ati pe ẹnyin kì
iṣe ti ara nyin?
20 Nitoripe a ti rà nyin ni iye kan:
nitorina ẹ mã yìn Ọlọrun logo ninu ara
nyin, ati ninu ẹmí nyin, ti iṣe ti Ọlọrun.

## ORI 7.

ṢUGBỌN nipa ti ọ̀ran ti ẹnyin ti kọwe si
mi: O dara fun ọkọnrin ki o má fi ara
kàn obirin.
2 Ṣugbọn nitori ki a le yàna àgbere silẹ,

Digitized by Google

ki olukuluku ọkọnrin ki o ni aya tirẹ̀, ati
ki olukuluku obirin ki o ni ọkọ tirẹ̀.
3 Ki ọkọ ki o mã ṣe ohun rere ti o yẹ
si aya rẹ̀: gẹgẹ bẹ̃ si li aya pẹlu si ọkọ
rẹ̀.
4 Aya kò li agbara lori ara rẹ̀, bikoṣe
ọkọ: gẹgẹ bẹ̃li ọkọ kò si li agbara lori ara
rẹ̀, bikoṣe aya.
5 Ẹ máṣe fà ara nyin sẹhin kuro lọdọ
ara nyin, bikoṣe nipa ifimọṣọkan nigbakan,
ki ẹnyin ki o le fi ara nyin fun àwẹ ati
adura igbà; ki ẹnyin ki o si tún jùmọ
pade, ki Satani ki o máṣe dán nyin wò
nitori aimaraduro nyin.
6 Ṣugbọn mo sọ eyi bi aṣẹ, kì iṣe nipa
ofin.
7 Ṣugbọn mo fẹ ki gbogbo enia ki o dabi
emi tikarami. Ṣugbọn olukuluku enia ni
ẹ̀bun tirẹ̀ lati ọdọ Ọlọrun wá, ọkan nipa
irú eyi, ati ekeji nipa irú eyini.
8 Nitorina mo wi fun awọn apọ́n ati opó
pe, O dara fun wọn bi nwọn ba wà gẹgẹ
bi emi ti wà.
9 Ṣugbọn bi nwọn kò ba le gbà a, ki
nwọn ki o gbeyawo: nitori o san lati
gbeyawo jù ati ṣe ifẹkufẹ lọ.
10 Ati awọn ti o ti gbeyawo ni mo paṣẹ
fun, ṣugbọn kì iṣe emi, bikoṣe Oluwa, Ki
aya ki o máṣe ti ọdọ ọkọ rẹ̀ kuro:
11 Ṣugbọn bi o ba si fi i silẹ, ki o wà li
ailọkọ mọ́, tabi ki o ba ọkọ rẹ̀ làja: ki ọkọ
ki o máṣe kọ̀ aya rẹ̀ silẹ.
12 Ṣugbọn awọn iyokù ni mo wi fun, kì
iṣe Oluwa: bi arakọnrin kan ba li aya ti
kò gbagbọ́, bi inu rẹ̀ ba si dùn lati ma ba
a gbé, ki on máṣe kọ̀ ọ silẹ.
13 Ati obirin ti o ni ọkọ ti kò gbagbọ́,
bi inu rẹ̀ ba si dùn lati ma ba a gbé, ki on
máṣe fi i silẹ.
14 Nitoriti a sọ alaigbagbọ́ ọkọ na di
mimọ́ ninu aya rẹ̀, a si sọ alaigbagbọ́ aya
na di mimọ́ ninu ọkọ rẹ̀: bikoṣe bẹ̃ awọn
ọmọ nyin iba jẹ alaimọ́; ṣugbọn nisisiyi
nwọn di mimọ́.
15 Ṣugbọn bi alaigbagbọ́ na ba lọ, jẹ ki
o mã lọ Arakọnrin tabi arabirin kan kò
si labẹ ìde, nitori irú ọ̀ran ba wọnni: ṣu-
gbọn Ọlọrun pè wa si alafia.
16 Nitoripe iwọ ti ṣe mọ̀, iwọ aya, bọya
iwọ o gbà ọkọ rẹ là? tabi iwọ ti ṣe mọ̀,
iwọ ọkọ, bọya iwọ o gbà aya rẹ là?
17 Ṣugbọn gẹgẹ bi Ọlọrun ti pín fun
olukuluku enia, bi Oluwa ti pè olukuluku,
bẹ̃ni ki o si mã rìn. Bẹ̃ni mo si nṣe ìlana
ninu gbogbo ijọ.
18 A ha pè ẹnikan ninu ikọla? ki o má
si ṣe di alaikọla mọ́. A ha pè ẹnikẹni li
aikọla? ki on máṣe kọla.
19 Ikọla asan ni, ati aikọla asan ni, bi-
koṣe pipa ofin Ọlọrun mọ́.
20 Ki olukuluku enia duro ninu ìpe ni-
pasẹ eyi ti a ti pè e.
21 A ha pè ọ, nigbati iwọ jẹ ẹrú? máṣe
kà a si: ṣugbọn bi iwọ ba le di omnira,
kuku ṣe eyini.
22 Nitori ẹniti a pè nipa ti Oluwa, ti iṣe
ẹrú, o di ẹni omnira ti Oluwa: gẹgẹ bẹ̃
pẹlu li ẹniti a pè li omnira, o di ẹrú Kristi.
23 A ti rà nyin ni iye kan; ki ẹnyin
máṣe jẹ ẹrú enia.
24 Ará, ki olukuluku enia ninu eyi ti a
pè e, ki o duro ninu ọkanna niwaju Ọlọrun.
25 Ṣugbọn nipa ti awọn wundia, emi kò
ni aṣẹ Oluwa: ṣugbọn mo fi ìmọ mi fun
nyin bi ẹniti o ri ãnu Oluwa gbà lati jẹ
olododo.
26 Nitorina mo rò pe eyi dara nitori wa-
halà isisiyi, mo ni, o dara fun enia ki o wà
bẹ̃.
27 A ti dè ọ mọ́ aya ri bi? iwọ máṣe wá
ọ̀na lati tú kuro. A ti tú ọ kuro lọwọ aya?
má si ṣe wá aya lati ni mọ́.
28 Ṣugbọn bi iwọ ba si gbeyawo, iwọ kò
dẹṣẹ: bi a ba si gbé wundia ni iyawo, on
kò dẹṣẹ. Ṣugbọn irú wọnni yio ni wahalà
nipa ti ara: ṣugbọn mo dá nyin si.
29 Ṣugbọn eyi ni mo wi, ará, pe kukuru
li akokò: o kù ki awọn ti o li aya ki o
dabi ẹnipe nwọn kò ni ri;
30 Ati awọn ti nsọkun, bi ẹnipe nwọn
kò sọkun ri; ati awọn ti nyọ̀, bi ẹnipe
nwọn kò yọ̀ ri; ati awọn ti nrà, bi ẹnipe
nwọn kò ni ri;
31 Ati awọn ti nlò ohun aiye yi bi ẹniti
kò ṣaṣeju: nitori iṣe aiye yi nkọja lọ.
32 Ṣugbọn emi nfẹ ki ẹnyin ki o wà li
aiṣaniyàn. Ẹniti iṣe alaili aya ama tọju
ohun ti iṣe ti Oluwa, bi on o ti ṣe le wù
Oluwa:
33 Ṣugbọn ẹniti o gbeyawo ama ṣe itọju
ohun ti iṣe ti aiye, bi on o ti ṣe wù aya rẹ̀.
34 Iyatọ si wà pẹlu larin abilekọ obirin
ati wundia. Obirin alailọkọ ama tọju ohun
ti iṣe ti Oluwa, ki on ki o le jẹ mimọ́ li ara
ati li ẹmí: ṣugbọn ẹniti a gbé niyawo ama
tọju ohun aiye, bi on o ti ṣe le wù ọkọ rẹ̀.
35 Eyi ni mo si nwi nitori ère ara nyin;
kì iṣe ikẹkun lati mu nyin, ṣugbọn nitori
eyi ti o tọ́, ati ki ẹnyin ki o le kọjusi Olu-
wa laisi ìyapa ọkàn.
36 Ṣugbọn bi ẹnikan ba rò pe on ti ṣe
ohun ti kò yẹ si wundia rẹ̀, bi o ba ti kọja

akokò ọdún rẹ̀, bi o si jẹ bẽ̃, jẹ ki o ṣe bi o
ti fẹ, on kò dẹṣẹ : jẹ ki nwọn gbé iyawo.
37 Ṣugbọn ẹniti o duro ṣinṣin li àiya rẹ̀,
ti ko ni aigbọdọ máṣe, ṣugbọn ti o li agba-
ra lori ifẹ ara rẹ̀, ti o si pinnu li àiya rẹ̀ pe,
on o pa wundia rẹ̀ mọ́, o ṣe rere.
38 Bẽ̃ si li ẹniti o fi funni ni igbeyawo,
o ṣe rere ; ṣugbọn ẹniti kò fi funni ni igbe-
yawo ṣe rere jù.
39 A fi ofin dè obirin mọ́ ọkọ rẹ̀ niwọn
igbati ọkọ rẹ̀ ba wà ; ṣugbọn bi ọkọ rẹ̀ ba
kú, on di omnira fun ẹnikẹni ti o wù u,
lati ba gbeyawo ; kìki ninu Oluwa nikan.
40 Ṣugbọn alabukun-fun julọ ni bi on
ba duro bẽ̃, nipa ìmọ mi : emi pẹlu si rò pe
mo li Ẹmí Ọlọrun.

## ORI 8.

ṢUGBỌN niti ohun ti a fi rubọ fun oriṣa,
awa mọ̀ pe gbogbo wa li o ni ìmọ.
Ìmọ ama fẹ̀ soke, ṣugbọn ifẹ ni ikọ́ni.
2 Bi ẹnikan ba si rò pe on mọ̀ ohun kan,
kò ti imọ̀ ohunkohun bi on iba ti mọ̀.
3 Ṣugbọn bi ẹnikẹni ba fẹ Ọlọrun, olu-
warẹ̀ li o di mimọ̀ fun u.
4 Nitorina niti jijẹ ohun wọnni ti a fi
rubọ fun oriṣa, awa mọ̀ pe ohun asan li
oriṣa li aiye, ati pe kò si Ọlọrun miran
bikoṣe ọkanṣoṣo.
5 Nitoripe bi nwọn tilẹ wà ti a npè li
ọlọrun, iba ṣe li ọrun tabi li aiye, (gẹgẹ bi
ọ̀pọ ọlọrun ti wà ati ọ̀pọ oluwa,)
6 Ṣugbọn fun wa Ọlọrun kan ni mbẹ,
Baba, lọwọ ẹniti ohun gbogbo ti wá, ati ti
ẹniti gbogbo wa iṣe ; ati Oluwa kanṣoṣo
Jesu Kristi, nipasẹ ẹniti ohun gbogbo wà,
ati awa nipasẹ rẹ̀.
7 Ṣugbọn irú ìmọ yi kò si ninu gbogbo
enia : ṣugbọn awọn ẹlomiran titi fi di isisi-
yi nfi ọkàn oriṣa jẹ ẹ bi ohun ti a fi rubọ
fun oriṣa ; ọkàn wọn ti o jẹ ailera si di
alaimọ́.
8 Ṣugbọn onjẹ kò yìn wa si Ọlọrun : ni-
toripe kì iṣe bi awa ba jẹ li awa sanju ;
tabi bi awa kò si jẹ li awa buruju.
9 Ṣugbọn ẹ mã kiyesara ki agbara nyin
yi ki o máṣe di ohun ìdugbolu fun awọn ti
iṣe ailera.
10 Nitoripe bi ẹnikan ba ri ti iwọ ti o ni
ìmọ ba joko tì onjẹ ni ile oriṣa, ọkàn ẹniti
iṣe ailera kì yio ha duro lati ma jẹ nkan
wọnni ti a fi rubọ fun oriṣa ?
11 Ati nipa ìmọ rẹ li alailera arakọnrin
na yio fi ṣegbé, ẹniti Kristi kú fun ?
12 Ṣugbọn nigbati ẹnyin ba nṣẹ̀ si awọn
arakọnrin bẽ̃, ti ẹnyin si npa alailera ọkàn
wọn lara, ẹnyin nṣẹ̀ si Kristi.
13 Nitorina, bi onjẹ ba mu arakọnrin
mi kọsẹ̀, emi kì yio si jẹ ẹran mọ́ niwọn
igbati aiye wà, ki emi ki o máṣe mu ara-
kọnrin mi kọsẹ̀.

## ORI 9.

APOSTELI kan kọ́ emi iṣe bi ? emi kò ha
wà li omnira ? emi ko ti ri Jesu Kristi
Oluwa wa ? iṣẹ mi kọ́ ẹnyin iṣe nipa ti
Oluwa ?
2 Bi emi kò ṣe Aposteli fun awọn ẹlo-
miran, ṣugbọn ni dajudaju Aposteli li emi
iṣe fun nyin : nitori èdidi iṣẹ Aposteli mi
ni nyin ninu Oluwa.
3 Èsi mi fun awọn ti nwadi mi li eyi pe,
4 Awa kò li agbara lati ma jẹ ati lati
ma mu bi ?
5 Awa kò ha li agbara lati ma mu aya ti
iṣe arabirin kiri, gẹgẹ bi awọn Aposteli
miran, ati bi awọn arakọnrin Oluwa, ati
Kefa ?
6 Tabi emi nikan ati Barnaba, awa kò
ha li agbara lati joko li aiṣiṣẹ ?
7 Tani ilọ si ogun nigba kan nipa inawo
on tikararẹ̀ ? tali o gbìn agbala ajara, ti kò
si jẹ ninu eso rẹ̀ ? tabi tani mbọ́ ọ̀wọ́ ẹran,
ti kò si jẹ ninu wàra ọ̀wọ́ ẹran na ?
8 Emi ha nsọ̀rọ nkan wọnyi bi enia ?
tabi ofin kò wi bakanna pẹlu bi ?
9 Nitoriti a ti kọ ọ ninu ofin Mose pe,
Iwọ kò gbọdọ pa malu ti ntẹ̀ alikama li
ẹnu mọ́. Ọlọrun ha nṣe itọju awọn malu
bi ?
10 Tabi o nsọ eyi patapata nitori wa ?
Nitõtọ nitori wa li a ṣe kọwe yi : ki ẹni-
kẹni ti nwà ilẹ ki o le ma wà ilẹ ni ireti ;
ati ki ẹniti npa ọkà ni ireti, ki o le ni ireti
lati ṣe olubapin ninu rẹ̀.
11 Bi awa ba ti fọnrugbin ohun ẹmí fun
nyin, ohun nla ha ni bi awa o ba ká eso
nkan nyin ti iṣe ti ara ?
12 Bi awọn ẹlomiran ba ṣe alabapin
ninu agbara yi lori nyin, awa kọ́ ẹniti o
kuku tọ́ fun ju ? Ṣugbọn awa kò lò agbara
yi ; ṣugbọn awa njìya ohun gbogbo, ki awa
ki o má ba ṣe ìdena fun ihin-rere Kristi.
13 Ẹnyin kò mọ̀ pe awọn ti nṣe iranṣẹ
nipa ohun mimọ́, nwọn ama jẹ ninu ohun
mimọ́ tempili ? ati awọn ti nduro tì pẹpẹ,
nwọn ama ṣe ajọpin pẹlu pẹpẹ ?
14 Gẹgẹ bẽ̃li Oluwa si ṣe ìlana pe, awọn
ti nwasu ihin-rere ki nwọn o si ma jẹ nipa
ihin-rere.
15 Ṣugbọn emi kò lò ọkan ninu nkan

Digitized by Google

wọnyi: bẹ̃li emi kò si kọwe nkan wọnyi,
nitori ki a le ṣe bẹ̃ gẹgẹ fun mi: nitoripe o
san fun mi ki emi kuku kú, jù ki ẹnikẹni
ki o sọ ogo mi di asan.
16 Nitoripe bi mo ti nwasu ihin-rere yi,
emi ko li ohunkohun ti emi o ṣogo si lori:
nitoripe aigbọdọ-máṣe wà lori mi; ani,
egbé ni fun mi bi emi kò wasu ihin-rere!
17 Nitoripe bi mo ba nṣe nkan yi tinu-
tinu mi, mo li ère kan: ṣugbọn bi o ba
ṣepe o lodi si ifẹ inu mi, a ti fi iṣẹ ipinfun-
ni ihin-rere le mi lọwọ.
18 Njẹ kini ha li ère mi? Nitõtọ ère
mi ni pe, nigbati mo ba nwasu ihin-rere,
ki emi ki o le fi ihin-rere Kristi funni lọfẹ,
ki emi ki o máṣe ba agbara mi jẹ ninu ihin-
rere.
19 Nitoripe bi mo ti jẹ omnira kuro
lọdọ gbogbo enia, ṣugbọn mo si ti sọ ara
mi di ẹrú fun gbogbo wọn, ki emi ki o le
jère pipọ.
20 Fun awọn Ju ni mo sọ ara mi dabi
Ju, ki emi ki o le jère awọn Ju; fun awọn
ti mbẹ labẹ ofin, bi ẹniti mbẹ labẹ ofin, ki
emi ki o le jère awọn ti mbẹ labẹ ofin;
21 Fun awọn ti o wà lailofin bi alailofin,
(ṣugbọn emi kì iṣe alailofin fun Ọlọrun,
ṣugbọn emi mbẹ labẹ ofin fun Kristi,) ki
emi ki o le jère awọn ti o wà lailofin.
22 Fun awọn alailera ni mo di alailera,
ki emi ki o le jère awọn alailera: mo fi
ara mi ṣe ohun gbogbo fun gbogbo enia, ki
emi ki o le tipasẹ ohun gbogbo gbà diẹ là.
23 Eyi ni mo si nṣe nitori ihin-rere, ki
emi ki o le jẹ alabapin ninu rẹ̀ pẹlu nyin.
24 Ẹnyin kò mọ̀ pe gbogbo awọn ti nsáre
ije kan, ni isáre, ṣugbọn ẹnikan ni igbà ère
na? Ẹ sáre bẹ̃, ki ẹnyin ki o le ri gbà.
25 Ati olukuluku ẹniti njijà ati bori ama
wà li airekọja ninu ohun gbogbo. Ṣugbọn
nwọn nṣe e lati gbà adé kan ti idibajẹ;
ṣugbọn awa eyi ti ki idibajẹ.
26 Nitorina bẹ̃ni emi nsáre, kì iṣe bi
ẹnipe ninu òkunkun; bẹ̃ni emi njà, kì iṣe
bi ẹnikan ti mbẹ́ afẹfẹ:
27 Ṣugbọn emi nrẹ̀ ara mi silẹ, mo si
nmu u wá sabẹ itẹriba: lẹhin igbati mo
ti wasu fun awọn ẹlomiran tan, nitori
ohunkohun, ki emi tikara mi ki o máṣe di
ẹni a o tanù.

## ORI 10.

PẸLUPẸLU, ará, emi kò fẹ ki ẹnyin ki
o ṣe alaimọ̀, bi gbogbo awọn baba wa
ti wà labẹ awọsanma, ti gbogbo wọn si là
okun já;
2 Ti a si baptisi gbogbo wọn si Mose
ninu awọsanma ati ninu okun;
3 Ti gbogbo wọn si ti jẹ onjẹ ẹmí kanna;
4 Ti gbogbo wọn si ti mu ohun mimu
ẹmí kanna: nitoripe nwọn nmu ninu
Apata ẹmí nì ti ntọ̀ wọn lẹhin: Kristi si li
Apata na.
5 Ṣugbọn ọ̀pọlọpọ wọn ni inu Ọlọrun
kò dùn si: nitoripe a bì wọn ṣubu li
aginjù.
6 Gbogbo nkan wọnyi si jasi apẹrẹ fun
wa nisisiyi, nikẹhin ki awa ki o máṣe ṣe
ifẹkufẹ si ohun buburu, gẹgẹ bi awọn pẹlu
ti ṣe ifẹkufẹ.
7 Bẹ̃ni ki ẹnyin ki o má si ṣe abọriṣa,
bi awọn miran ti ṣe ninu wọn; gẹgẹ bi a
ti kọ ọ pe, Awọn enia na joko lati mã
jẹ ati lati mã mu, nwọn si dide lati mã
ṣire.
8 Bẹ̃ni ki awa ki o má si ṣe àgbere bi
awọn ẹlọmiran ti ṣe, ti ẹgba-mọkanlale-
ẹgbẹrun enia ṣubu ni ijọ kan ninu wọn.
9 Bẹ̃ni ki awa ki o máṣe dán Kristi wò,
gẹgẹ bi awọn ẹlomiran pẹlu ninu wọn ti
dán a wò, ti a si fi ejò run wọn.
10 Bẹ̃ni ki ẹnyin ki o máṣe kùn ninu
nyin, gẹgẹ bi awọn ẹlomiran pẹlu ninu
wọn ti kùn, a si run wọn lati ọwọ́ oluparun
nì wá.
11 Gbogbo nkan wọnyi ti o ṣẹ si wọn si
jasi apẹrẹ fun wa: a si kọwe wọn lati jẹ
ikilọ̀ fun awa, ẹniti igbẹhin aiye de bá.
12 Nitorina ẹnikẹni ti o ba rò pe on
duro, ki o kiyesara, ki o má ba ṣubu.
13 Kò sá ti isi idanwò kan ti o ti bá
nyin, bikoṣe irú eyiti o mọ̀ niwọn fun
enia: ṣugbọn olododo li Ọlọrun, ẹniti kì
yio jẹ ki a dan nyin wò jù bi ẹnyin ti le
gbà; ṣugbọn on o ṣe ìlana kan pẹlu ninu
idanwò na lati là, ki ẹnyin ki o le gbà a.
14 Nitorina, ẹnyin olufẹ mi ọwọn, ẹ sá
fun oriṣa sisìn.
15 Emi nsọrọ bi ẹnipe fun awọn ọlọ́gbọn
enia; ẹ rò eyiti mo wi.
16 Ago ibubún ti awa nsure si, ìdapọ
ẹ̀jẹ Kristi kọ́ iṣe? Akara ti awa mbù,
ìdapọ ara Kristi kọ́ iṣe?
17 Nitoripe awa ti iṣe ọ̀pọlọpọ jasi akara
kan, ati ara kan: nitoripe gbogbo wa ni
iṣe ajọpin ninu akara kan nì.
18 Wò Israeli nipa ti ara: awọn ti njẹ
ninu ohun ẹbọ ki nṣe alabapin nibi pẹpẹ?
19 Njẹ kini emi nwi? pe, oriṣa ni nkan,
tabi ohun ti a fi rubọ fun oriṣa ni nkan?
20 Ṣugbọn mo ni, ohun ti awọn Keferi fi
nrubọ, nwọn fi nrubọ fun awọn ẹmi èṣu,

Digitized by Google

kì iṣe fun Ọlọrun: emi kò si fẹ ki ẹnyin ki
o ba awọn ẹmi èṣu ṣe alabapin.
21 Ẹnyin kì yio le mu ninu ago Oluwa,
ati ninu ago awọn ẹmi èṣu: ẹnyin kì o le
ṣe ajọpin lori tabili Oluwa, ati lori tabili
ẹmi èṣu.
22 Awa ha nmu Oluwa jowú bi? awa ha
li agbara jù u lọ?
23 Ohun gbogbo li o tọ́ fun mi, ṣugbọn
ohun gbogbo kì iṣe ti ègbe: ohun gbogbo
li o tọ́ fun mi, ṣugbọn ohun gbogbo kì iṣe
ti ẹkọ́.
24 Ki ẹnikẹni máṣe tọju kìki ohun ti
ara rẹ̀ mọ́, ṣugbọn olukuluku ohun ti
ọmọnikẹji rẹ̀.
25 Ohunkohun ti a ntà li ọjà on ni ki ẹ
mã jẹ, ẹ máṣe bère ọ̀rọ kan nitori ẹri-ọkàn.
26 Nitoripe ti Oluwa ni ilẹ ati ẹkún rẹ̀.
27 Bi ọkan ninu awọn ti kò gbagbọ́ ba
pè nyin si ibi àse kan, bi ẹnyin ba si fẹ ilọ;
ohunkohun ti a ba gbé kalẹ niwaju nyin
ni ki ẹ jẹ, ẹ máṣe bère ọ̀rọ kan nitori ẹri-
ọkàn.
28 Ṣugbọn bi ẹnikan ba wi fun nyin pe,
A fi eyi rubọ fun oriṣa, ẹ máṣe jẹ ẹ nitori
ẹniti o fi hàn nyin, ati nitori ẹri-ọkàn:
nitoripe ti Oluwa ni ilẹ, ati ẹkún rẹ̀:
29 Mo ni, ẹri-ọkàn, kì iṣe ti iwọ tikararẹ,
ṣugbọn ti ẹlomiran nì: nitori kili a o ṣe
bá omnira mi wijọ nipa ọkàn ẹlomiran si?
30 Nitoripe bi emi ba ṣe alabapin nipa
idupẹ, ẽhatiṣe ti a fi nsọ̀rọ buburu si mi
nitori eyi ti mo ti dupẹ fun?
31 Nitorina bi ẹnyin ba njẹ, bi ẹnyin ba
si nmu, tabi ohunkohun ti ẹnyin ba nṣe, ẹ
ma ṣe gbogbo wọn fun ogo Ọlọrun.
32 Ẹ máṣe fi ohun idugbolù si ọ̀na ẹni-
kẹni, iba ṣe awọn Ju, tabi wọn Hellene,
tabi ijọ enia Ọlọrun:
33 Gẹgẹ bi emi ti nwù gbogbo enia li
ohun gbogbo, ti emi kò si wá ère emi
tikarami, ṣugbọn ère awọn ọ̀pọlọpọ, ki
nwọn ki o le là.

## ORI 11.

E MÃ ṣe ọmọ lẹhin mi, gẹgẹ bi emi pẹlu
ti ṣe ọmọ-ẹhin Kristi.
2 Ará, mo yìn nyin nisisiyi, bi ẹnyin ti
nranti mi ninu ohun gbogbo, ti ẹnyin si
npa ìlana wọnni mọ́, gẹgẹ bi mo ti fi silẹ
fun nyin.
3 Ṣugbọn mo fẹ ki ẹnyin ki o mọ̀ pe,
Kristi li ori olukuluku ọkọnrin; ori obirin
si li ọkọ rẹ̀; ati ori Kristi si li Ọlọrun.
4 Olukuluku ọkọnrin ti ngbadura tabi
ti nsọtẹlẹ ni bibò ori rẹ̀, o ṣe alaibọ̀wọ fun
ori rẹ̀.
5 Ṣugbọn olukuluku obirin ti ngbadura
tabi ti nsọtẹlẹ li aibò ori rẹ̀, o ṣe alaibọ̀wọ
fun ori rẹ̀: nitori eyini jẹ bakanna, gẹgẹ
bi ẹnipe o fári.
6 Nitoripe bi obirin ba ṣe alaibori rẹ̀, ẹ
jẹ ki a fári rẹ̀ pẹlu: ṣugbọn bi o ba ṣepe
ohun itiju ni fun obirin lati rẹrun tabi lati
fári rẹ̀, ẹ jẹ ki o bò ori rẹ̀.
7 Nitõtọ kò tilẹ tọ́ ki ọkọnrin ki o má
bò ori rẹ̀, niwọn bi on ti iṣe apẹrẹ ati ogo
Ọlọrun: ṣugbọn obirin ni iṣe ogo ọkọnrin.
8 Nitoripe a kò mu ọkọnrin ti ara
obirin wá; ṣugbọn obirin li a mu ti ara
ọkọnrin wá.
9 Bẽni a kò dá ọkọnrin nitori obirin;
ṣugbọn a da obirin nitori ọkọnrin.
10 Nitori idi eyi li o fi yẹ fun obirin
lati ni ọlá li ori rẹ̀, nitori awọn angeli.
11 Ṣugbọn ọkọnrin kò le wà laisi obirin,
bẽni obirin kò le wà laisi ọkọnrin, nipa ti
Oluwa.
12 Nitoripe bi obirin ti ti ara ọkọnrin
wá, gẹgẹ bẽli ọkọnrin tipasẹ obirin wá
pẹlu; ṣugbọn lọwọ Ọlọrun li ohun gbogbo
ti wá.
13 Ẹ rò o ninu ẹnyin tikara nyin: o ha
yẹ li oju nyin ki obirin ki o mã gbadura si
Ọlọrun laibori rẹ̀?
14 Ani ẹda tikararẹ̀ pãpã kò kọ́ nyin pe,
bi ọkọnrin ba ni irun gigun, ohun itiju ni
fun u?
15 Ṣugbọn bi obirin ba ni irun gigun,
ogo ni fun u: nitoriti a fi irun rẹ̀ fun u
lati fi ṣe iboju.
16 Ṣugbọn bi ẹnikẹni ba dabi aṣagọn enia
ninu nyin, awa kò ni irú ìwa bẹ̃, tabi ijọ
enia Ọlọrun.
17 Njẹ emi kò yìn nyin nitori eyiti emi
nfi aṣẹ fun nyin nisisiyi pe, ẹnyin pejọ pọ̀
kì iṣe fun rere, ṣugbọn fun buburu nyin.
18 Nitori ṣaju ohun gbogbo mo gbọ́ pe,
nigbati ẹnyin pejọ ni ile Ọlọrun, ìyapa
mbẹ ninu nyin; mo si gbà a gbọ́ li apakan.
19 Nitoripe kò le ṣe ki o má si awọn
aladamọ̀ ninu nyin pẹlu, ki awọn ti iṣe ẹni
itẹwọgbà ba le fi ara hàn.
20 Nitorina nigbati ẹnyin ba pejọ pọ̀ si
ibi kan, eyi kì iṣe lati jẹ Onjẹ Alẹ Oluwa.
21 Nitoripe ni jijẹ ẹnikan ngbà onjẹ tirẹ̀
ṣaju ẹnikeji: ebi npa ẹnikan, ẹnikeji si
nmu amupara.
22 Kinla? ẹnyin kò ni ile nibiti ẹnyin
o ma jẹ, ti ẹnyin o ma mu? tabi ẹnyin
ngàn ijọ enia Ọlọrun, ẹnyin si ndojuti

Digitized by Google

awọn ti kò ni? Kili emi o wi fun nyin?
emi o ha yìn nyin ninu eyi? emi kò yìn'
nyin rara.
23 Nitoripe lọwọ Oluwa ni mo ti gbà
eyini ti mo ti fifun nyin pẹlu, pe Jesu
Oluwa li oru ọjọ na ti a ṣofofo rẹ̀, o mu
akara:
24 Nigbati o si dupẹ, o bù u, o si wipe,
Gbà, jẹ: eyiyi li ara mi ti a ṣẹ fun nyin:
ẹ ma ṣe eyi ni iranti mi.
25 Gẹgẹ bẹ̃ pẹlu li o si mu ago, lẹhin
igbati o jẹun tan, o nwipe, Ago yi ni majẹ-
mu titun ẹ̀jẹ mi: nigbakugba ti ẹnyin ba
nmu u, ẹ ma ṣe eyi ni iranti mi.
26 Nitori nigbakugba ti ẹnyin ba' njẹ
akara yi, ti ẹnyin ba si nmu ago yi, ẹnyin
nfi ikú Oluwa hàn titi yio fi de.
27 Nitorina ẹnikẹni ti o ba jẹ akara yi,
ti o si mu ago Oluwa yi laiyẹ, on o jẹbi ara
ati ẹ̀jẹ Oluwa.
28 Ṣugbọn jẹ ki enia ki o wadi ara rẹ̀
daju, bẹ̃ni ki o jẹ ninu akara na, ki o si
mu ninu ago na.
29 Nitori ẹnikẹni ti o ba njẹ, ti o ba si
nmu laiyẹ, o njẹ, o si nmu ẹbi fun ara rẹ̀,
kò si mọ̀ ara Oluwa.
30 Nitori idi eyi li ọ̀pọlọpọ fi di alailera
ati olokunrun ninu nyin, ti ọ̀pọlọpọ si sùn.
31 Nitoripe bi awa ba jẹ dá ara wa lẹjọ,
a kì yio si da wa lẹjọ.
32 Ṣugbọn nigbati a ba ndá wa lẹjọ, lati
ọwọ́ Oluwa li a ti nnà wa, ki a máṣe dá wa
lẹbi pẹlu araiye.
33 Nitorina, ará mi, nigbati ẹnyin ba
pejọ lati jẹun, ẹ mã duro dè ara nyin.
34 Bi ebi ba si npa ẹnikẹni, ki o jẹun ni
ile rẹ̀; ki ẹnyin ki o máṣe pejọ fun ẹbi ara
nyin. Iyokù li emi o tò lẹsẹsẹ nigbati mo
ba de.

## ORI 12.

NJẸ ará, emi ko fẹ ki ẹnyin ki o wà li
òpe nipa ti ẹ̀bun ẹmí.
2 Ẹnyin sá mọ̀ bi ẹnyin ti jẹ Keferi ti a
fà lọ sọdọ odi oriṣa wọnyi, gẹgẹ bi a ti dari
nyin.
3 Nitorina mo wi fun nyin lati mọ̀ pe,
kò si ẹnikẹni ti nsọ̀rọ nipa Ẹmí Ọlọrun, ti
o le pè Jesu li ẹni ifibu: ati pe, kò si ẹniti
o le wipe, Oluwa ni Jesu iṣe, bikoṣe nipa
Ẹmí Mimọ́.
4 Nisisiyi onirũru ẹ̀bun li o sá wà, ṣu-
gbọn ọkan li Ẹmí.
5 Ati onirũru iṣẹ iranṣẹ li o si wà, ṣu-
gbọn Oluwa kanna ni.
6 Ati alarabara iṣẹ li o si wà, ṣugbọn
Ọlọrun kanna ni nṣiṣẹ gbogbo wọn ninu
gbogbo wọn.
7 Ṣugbọn a nfi ifihàn Ẹmí fun olukulu-
ku enia lati jère nipasẹ rẹ̀.
8 Nitoriti a fi ọ̀rọ ọgbọ́n fun ẹnikan nipa
ti Ẹmí; ati fun ẹlomiran ọ̀rọ ìmọ nipa
Ẹmí kanna;
9 Ati fun ẹlomiran igbagbọ́ nipa Ẹmí
kanna; ati fun ẹlomiran ẹ̀bun imularada
nipa Ẹmí kanna;
10 Fun ẹlomiran iṣẹ iyanu iṣe; fun ẹlo-
miran isọtẹlẹ; fun ẹlomiran ìmọ ẹmí; fun
ẹlomiran onirũru ède ifọ̀; fun ẹlomiran
itumọ̀ ède:
11 Ṣugbọn gbogbo wọnyi li ẹnikan nì,
ani Ẹmí kanna nṣe, o npín fun olukuluku
gẹgẹ bi o ti wù u.
12 Nitoripe gẹgẹ bi ara ti jẹ ọkan, ti o si
li ẹ̀ya pipọ, ti gbogbo ẹ̀ya ara kanna ti iṣe
ọ̀pọ̀ọpọ di ara kan: gẹgẹ bẹ̃ni Kristi pẹlu.
13 Nitoripe nipa Ẹmí kan li a ti baptisi
gbogbo wa sinu ara kan, iba ṣe Ju, iba ṣe
Hellene, iba ṣe ẹru, iba ṣe omnira; a si ti
mu gbogbo wa mu ninu Ẹmí kan.
14 Nitoripe ara kì iṣe ẹ̀ya kan, bikoṣe
ọ̀pọlọpọ.
15 Bi ẹsẹ ba si wipe, Nitoriti emi kì iṣe
ọwọ́, emi kì iṣe ti ara; nitorina on kì ha
ṣe ti ara bi?
16 Bi etí ba si wipe, Nitoriti emi ki iṣe
oju, emi kì iṣe ti ara; nitorina on kì ha ṣe
ti ara bi?
17 Njẹ bi gbogbo ara ba jẹ oju, nibo ni
igbọràn iba gbé wà? Bi gbogbo rẹ̀ ba si jẹ
igbọràn, nibo ni igbõrùn iba gbé wà?
18 Ṣugbọn nisisiyi Ọlọrun ti fi olukulu-
ku awọn ẹ̀ya sinu ara, gẹgẹ bi o ti wù u.
19 Bi gbogbo wọn ba si jẹ ẹ̀ya kan, nibo
li ara iba gbé wà?
20 Ṣugbọn nisisiyi ní nwọn jẹ ọ̀pọlọpọ
ẹ̀ya, ṣugbọn ara kan ni.
21 Bẹ̃ni oju kò le wi fun ọwọ́ pe, emi kò
ni ifi ọ ṣe: tabi ki ori wi ẹ̀wẹ fun ẹsẹ pe,
emi kò ni ifi nyin ṣe.
22 Ṣugbọn pẹlupẹlu awọn ẹ̀ya ara wọnni
ti o dabi ẹnipe nwọn ṣe ailera jù, awọn li a
kò le ṣe alaini:
23 Ati awọn ẹ̀ya ara wọnni ti awa rò pe
nwọn ṣe ailọlá, lori wọnyi li awa si nfi ọlá
si lọpọlọpọ; bẹ̃ni ibi aiyẹ wa si ni ẹyẹ
lọpọlọpọ.
24 Nitoripe ibi ti o li ẹyẹ li ara wa kò ṣe
alaini: ṣugbọn Ọlọrun ti ṣe ara lọkan, o si
fi ọ̀pọlọpọ ọlá fun ibi ti o ṣe alaini:
25 Ki ìyapa ki o máṣe si ninu ara; ṣu-

Digitized by Google

gbọn ki awọn ẹ̀ya ara ki o le ma ṣe aniyan
kanna fun ara wọn.
26 Ati bi ẹ̀ya kan ba njìya, ki gbogbo
ẹ̀ya si jùmọ ba a jìya ; tabi bi a ba nṣe ọlá
fun ẹ̀ya kan, ki gbogbo ẹ̀ya iyokù jùmọ ba
a yọ̀.
27 Njẹ nisisiyi ẹnyin ni ara Kristi nitõ-
tọ, ati pàtaki ẹ̀ya ninu rẹ̀.
28 Ọlọrun si gbé awọn miran kalẹ ninu
ijọ, ekini awọn aposteli, ekeji awọn woli,
ẹkẹta awọn olukọni, lẹhin eyini iṣẹ iyanu,
nigbana li ẹ̀bun imularada, iranlọwọ, iṣo-
lori, onirũru ède.
29 Gbogbo wọn ni iṣe aposteli bi? gbo-
gbo wọn ni iṣe woli bi? gbogbo wọn ni iṣe
olukọni bi? gbogbo wọn ni ha nṣe iṣẹ iya-
nu bi?
30 Gbogbo wọn li o ha li ẹ̀bun imularada
bi? iṣe gbogbo wọn ni nfi ède fọ̀ bi? gbo-
gbo wọn ni nṣe itumọ̀ bi?
31 Ṣugbọn ẹ ma fi itara ṣafẹri ẹ̀bun ti o
dara julọ: ṣugbọn mo fi ọ̀na kan ti o tayọ
julọ hàn nyin.

## ORI 13.

BI mo tilẹ nfi ède enia ati ti angeli sọ̀rọ,
ti emi kò si ni ifẹ, emi dabi idẹ ti
ndún, tabi bi ohun-èlo olohùn goro.
2 Ani bi mo tilẹ ni ẹ̀bun isọtẹlẹ, ti mo si
moye gbogbo ohun ijinlẹ, ati gbogbo ìmọ;
ati bi mo tilẹ ni gbogbo igbagbọ̀, tobẽ ti
mo le ṣí awọn òke nla nipò, ti emi kò si ni
ifẹ, asan ni mi.
3 Ani bi mo tilẹ fi gbogbo ẹrù mi jìn lati
fi bọ́ awọn talakà, ati bi mo si fi ara mi
funni ni sisun ninu iná, ti emi kò si ni
ifẹ, kò ṣe ère kan fun mi.
4 Nitori ifẹ ama jìya pẹ titi, o si ṣeun;
ifẹ kì iṣe ilara; ifẹ kì igbé ara rẹ̀ ga, on kì
si ifẹ̀ soke.
5 On kì ifi ara rẹ̀ ṣe ohun ti kò tọ́, bẽni
kì iwá eyi ti ṣe ti ara rẹ̀, a kì imu u binu
kánkan, bẽni kì igbiro ohun buburu;
6 Ifẹ kì iyọ̀ si ìwa buburu, ṣugbọn amã
yọ̀ ninu otitọ;
7 On ama gbiyanju ohun gbogbo, a si ma
gbà ohun gbogbo gbọ́, ama reti ohun gbo-
gbo, a si ma fi àiya rán ohun gbogbo.
8 Ifẹ kì iyẹ̀ titi lai: ṣugbọn bi o ba ṣepe
isọtẹlẹ li o wà, nwọn o dopin; bi o ba ṣepe
ẹ̀bun ahọn ni, nwọn o dakẹ; bi o ba ṣepe
ìmọ ni, on o di asan.
9 Nitoripe awa ni ìmọ li apakan, awa si
nsọtẹlẹ li apakan.
10 Ṣugbọn nigbati eyi ti o pé ba de, eyi
ti iṣe ti apakan yio ti ọ̀na kuro.
11 Nigbati mo wà li ewe, emi ama sọ̀rọ
bi ewe, emi ama moye bi ewe, emi a si ma
rò bi ewe: ṣugbọn nigbati mo di ọkọnrin
tan, mo fi ìwa ewe silẹ.
12 Nitoripe awa nriran baibai ninu awo-
jiji; ṣugbọn nigbana ni ifojukoju: nisisiyi
mo mọ̀ li apakan; ṣugbọn nigbana li emi o
mọ̀ gẹgẹ bi mo si ti di mimọ̀ pẹlu.
13 Njẹ nisisiyi igbagbọ́, ireti, ati ifẹ
mbẹ, awọn mẹta yi: ṣugbọn eyiti o tobi jù
ninu wọn ni ifẹ.

## ORI 14.

EMA lepa ifẹ, ki ẹ si ma ṣafẹri ẹ̀bun ti
iṣe ti Ẹmí, ṣugbọn jù gbogbo wọn lọ
ki ẹ kuku le ma sọtẹlẹ.
2 Nitori ẹniti nsọ̀rọ li ède aimọ̀, kò sọ̀rọ
si enia, bikoṣe si Ọlọrun: nitori kò si ẹniti
o gbọrọ rẹ̀; ṣugbọn nipa ti ẹmí o nsọ̀rọ
ohun ijinlẹ:
3 Ṣugbọn ẹniti nsọtẹlẹ, nsọ̀rọ si enia fun
imuduro, ati igbiyanju, ati itunu wọn.
4 Ẹniti nsọ̀rọ li ède aimọ̀ ngbà ara rẹ̀
niyanju; ṣugbọn ẹniti nsọtẹlẹ ngbà ijọ
niyanju.
5 Emi fẹ ki gbogbo nyin le ma fi ède fọ̀,
ṣugbọn ki ẹnyin kuku ma sọtẹlẹ: nitori
ẹniti nsọtẹlẹ pọ̀ju ẹniti nfi ède fọ̀ lọ, ayaṣe-
bi o ba nṣe itumọ̀, ki ijọ ki o le kọ́ ẹkọ́.
6 Nisisiyi, ará, bi mo wá si arin nyin, ti
emi nfi ède fọ̀, ère kili emi o jasi fun nyin,
bikoṣepe mo ba nsọ fun nyin, yala nipa
iṣipaya, tabi nipa imoye, tabi nipa isọtẹlẹ
tabi nipa ẹkọ́?
7 Ati pãpã awọn nkan ti kò li ẹmí ti
ndún, ibã ṣe fère tabi dùru, bikoṣepe ìyatọ
ba wà ninu ohùn wọn, a o ti ṣe le mọ̀ ohun
ti a nfun fère tabi ti a nlù dùru si?
8 Nitoripe bi ohùn ipè ba ṣe aidanilojn,
tani o mu ara rẹ̀ silẹ fun ogun?
9 Bẽ gẹgẹ si li ẹnyin, bikoṣepe ẹnyin ba
nfi ahọ́n nyin sọrọ ti o ye ni, a o ti ṣe le
mọ̀ ohun ti a nwi? nitoripe ẹnyin o sọ̀rọ
si ofurufu.
10 O le jẹ pe ọ̀pọlọpọ irú ohùn ni mbẹ
li aiye, ko si si ọkan ninu wọn ti o ṣe alai-
ni apẹrẹ.
11 Nitorina bi emi kò mọ̀ idi ohùn na,
emi o jasi alaigbede si ẹniti nsọ̀rọ, ẹniti
nsọ̀rọ yio si jasi alaigbede si mi.
12 Niwọn bi ẹnyin ti ni itara fun ẹ̀bun
ẹmí gbogbo, gẹgẹ bẽni ki ẹ si mã ṣe afẹri
lati tayọ fun idàgbàsoke ijọ.
13 Nitorina ẹ jẹ ki ẹniti nsọ̀rọ li ède
aimọ̀, gbadura ki o le mã ṣe itumọ̀.
14 Nitoripe bi emi ba ngbadura li ède

aimọ̀, ẹmí mi ngbadura nitõtọ, ṣugbọn
imoye mi jasi alaileso.
15 Njẹ kini rè? Emi o fi ẹmí gbadura,
emi o si fi imoye gbadura pẹlu: emi o fi
ẹmí kọrin, emi o si fi imoye kọrin pẹlu.
16 Tabi nigbati iwọ ba súre nipa ti ẹmí,
ẹniti mbẹ ni ipò alaikọ́gbọn yio ti ṣe wipe,
Amin si idupẹ rẹ, on kò sa gbọ́ bi iwọ ti
wi?
17 Nitori iwọ dupẹ gidigidi nitõtọ,
ṣugbọn ẹlomiran kò li ẹkọ́ lati mu u duro.
18 Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun mi, nitoriti
emi nfi ède pupọ sọ̀rọ jù gbogbo nyin lọ:
19 Ṣugbọn mo fẹ ki nkuku fi ìmọ mi sọ
ọ̀rọ marun ninu ijọ, lati fi ohùn mi kọ́
awọn ẹlomiran pẹlu, jù ẹgbãrun ọ̀rọ li ède
aimọ̀ lọ.
20 Ará, ẹ máṣe jasi ọmọde ni imoye:
ṣugbọn ẹ jasi ọmọde li arankan, ṣugbọn ni
imoye ki ẹ jasi àgba.
21 A ti kọ ọ ninu ofin pe, Nipa awọn
enia ahọn miran ati ète miran li emi o fi
sọ̀rọ fun awọn enia yi; ṣugbọn fun gbogbo
eyi, nwọn ki yio gbohùn mi sibẹ̀, li Oluwa
wi.
22 Nitorina awọn ahọn jasi àmi kan, ki
iṣe fun awọn ti o gbagbọ́, bikoṣe fun awọn
alaigbagbọ́: ṣugbọn isọtẹlẹ ki iṣe fun awọn
ti kò gbagbọ́, bikoṣe fun awọn ti o gbagbọ́.
23 Njẹ bi gbogbo ijọ ba pejọ si ibi kan,
ti gbogbo nwọn si nfi ède fọ̀, bi awọn ti iṣe
alailọ́gbọn ati alaigbagbọ́ ba wọle wá, nwọn
ki yio ha wipe ẹnyin nṣe wère?
24 Ṣugbọn bi gbogbo nyin nsọtẹlẹ, ti
ẹnikan ti kò gbagbọ́ tabi alaikẹkọ́ ba wọle
wá, gbogbo nyin ni yio fi oyé ẹṣẹ yé e,
gbogbo nyin ni yio ṣe idajọ rẹ̀:
25 Bẽli a si fi aṣiri àiya rẹ̀ hàn; on o si
wolẹ yio gbadura si Ọlọrun, yio si ròhin
wipe, Ọlọrun mbẹ larin nyin nitõtọ.
26 Njẹ ẽhatiṣe, ará? nigbati ẹnyin pejọ
pọ̀, ti olukuluku nyin ni psalmu kan, ẹkọ́
kan, ède kan, ifihàn kan, itumọ̀ kan. Ẹ
mã ṣe ohun gbogbo lati muni-duro.
27 Bi ẹnikan ba nfi ède aimọ̀ fọ̀, ki o jẹ
enia meji, tabi bi o tilẹ pọ̀ tan, ki o jẹ
mẹta, ati eyini lẹsẹsẹ; ki ẹnikan si ṣe
itumọ̀.
28 Ṣugbọn bi kò ba si onitumọ̀, ki o pa
ẹnu rẹ̀ mọ́ ninu ijọ; ẹ jẹ ki o ma ba ara rẹ̀
sọ̀rọ ati Ọlọrun.
29 Jẹ ki awọn woli meji bi mẹta sọrọ,
ki awọn ẹlomiran si ṣe idajọ.
30 Bi a ba si fi ohunkohun hàn ẹniti o
joko leti ibẹ̀, jẹ ki ẹni iṣaju pa ẹnu rẹ̀ mọ́.
31 Li ọkọkan ni ki gbogbo nyin ma
sọtẹlẹ, ki gbogbo nyin ba le li ẹkọ́, ki
gbogbo nyin le ni itunu.
32 Ẹmí awọn woli a si ma tẹriba fun
awọn woli.
33 Nitori Ọlọrun ki iṣe olupilẹṣẹ ohun
rudurudu, bikoṣe ti alafia, gẹgẹ bi o ti jasi
ninu gbogbo ijọ enia mimọ́.
34 Jẹ ki awọn obirin nyin dakẹ ninu
ijọ: nitori a kò fifun wọn lati fọhùn;
ṣugbọn a pa a laṣẹ fun wọn lati wà labẹ
itẹriba, gẹgẹ bi ofin pẹlu ti wi.
35 Bi nwọn ba si nfẹ kọ́ ohunkohun, ki
nwọn ki o bère lọwọ ọkọ wọn ni ile: nitori
ohun itiju ni fun awọn obirin lati ma
fọhùn ninu ijọ.
36 Kini rè? lọdọ nyin li ọ̀rọ Ọlọrun ti
jade ni? tabi o tọ̀ nyin wá nikan?
37 Bi ẹnikẹni ba rò ninu ara rẹ̀ pe woli
li on iṣe, tabi ẹniti o li ẹmí, ki o jẹwọ pe
awọn ofin Oluwa ni nkan ti mo kọwe wọn
si nyin.
38 Ṣugbọn bi ẹnikan ba jasi òpe, ẹ jẹ ki
o jasi òpe.
39 Nitorina, ará, ẹ mã fi itara ṣafẹri lati
sọtẹlẹ, ki ẹ má si ṣe danilẹkun lati fi ède fọ̀.
40 Ẹ mã ṣe ohun gbogbo tẹyẹtẹyẹ ati
lẹsẹlẹsẹ.

## ORI 15.

PẸLUPẸLU, ará, emi nròhin ìhin-rere na
fun nyin ti mo ti wasu fun nyin, eyiti
ẹnyin pẹlu si ti gbà, ninu eyi ti ẹnyin si
duro;
2 Nipasẹ eyiti a o fi gbà nyin là pẹlu,
bi ẹnyin ba di ọ̀rọ ti mo ti wasu fun nyin
mu ṣinṣin, bikoṣepe ẹnyin ba gbagbọ́ lasan.
3 Nitoripe ṣiwaju ohun gbogbo mo fi
eyiti emi pẹlu ti gbà le nyin lọwọ, bi
Kristi ti kú nitori ẹ̀ṣẹ wa gẹgẹ bi iwe-mimọ́
ti wi;
4 Ati pe a sinkú rẹ̀, ati pe o jinde ni ijọ
kẹta gẹgẹ bi iwe-mimọ́ ti wi:
5 Ati pe a ri i lọdọ Kefa, lẹhin eyini a si
ri i lọdọ awọn mejila:
6 Lẹhin eyini a ri i lẹ̃kanṣoṣo lọdọ awọn
ará ti o jù ẹ̃dẹgbẹta lọ; apakan ti o pọ̀ju
ninu wọn wà titi fi di isisiyi, ṣugbọn awọn
diẹ ti dubulẹ sùn.
7 Lẹhin eyini a ri i lọdọ Jakọbu; lẹhin
na li a ri i lọdọ gbogbo awọn Aposteli.
8 Ati nikẹhin gbogbo wọn o farahàn mi
pẹlu, bi ẹni ti a bí ṣiwaju akokò rẹ̀.
9 Nitori emi li ẹniti o kere jùlọ ninu
awọn Aposteli, ti emi ko yẹ li ẹniti a ba pè
li Aposteli, nitoriti mo ti ṣe inunibini si
ijọ enia Ọlọrun.

Digitized by Google

10 Ṣugbọn nipa ore-ọfẹ Ọlọrun, mo ri bi
mo ti ri: ore-ọfẹ rẹ̀ ti a fifun mi kò si jẹ
asan; ṣugbọn mo ṣiṣẹ lọpọlọpọ jù gbogbo
wọn lọ: ṣugbọn kì iṣe emi, bikoṣe ore-ọfẹ
Ọlọrun ti o wà pẹlu mi.
11 Nitorina ibã ṣe emi tabi awọn ni,
bẽli awa wasu, bẽli ẹnyin si gbagbọ́.
12 Njẹ bi a ba nwasu Kristi pe o ti
jinde kuro ninu okú, ẽhatiṣe ti awọn mi-
ran ninu nyin fi wipe, ajinde okú kò si?
13 Ṣugbọn bi ajinde okú kò si, njẹ
Kristi kò jinde:
14 Bi Kristi kò ba si jinde, asan ni
iwasu wa, asan si ni igbagbọ́ nyin pẹlu.
15 Pẹlupẹlu, awa si jasi ẹlẹri eke fun
Ọlọrun; nitoriti awa njẹri Ọlọrun pe o ti
jí Kristi dide: ẹniti on kò jí dide, bi o ba
ṣepe awọn okú kò jinde?
16 Nitoripe bi awọn okú kò jinde, njẹ,
a kò jí Kristi dide:
17 Bi a kò ba si jí Kristi dide, asan ni
igbagbọ́ nyin; ẹnyin wà ninu ẹ̀ṣẹ nyin
sibẹ.
18 Njẹ awọn pẹlu ti o dubulẹ sùn ninu
Kristi ṣegbé.
19 Bi o ba ṣepe ni kìki aiye yi nikan li
awa ni ireti ninu Kristi, awa jasi òtoṣi
jùlọ ninu gbogbo enia.
20 Ṣugbọn nisisiyi Kristi ti jinde kuro
ninu okú, o si di ákọbi ninu awọn ti o sùn.
21 Nitori igbati o ti ṣepe lati ipa ọdọ
enia ni ikú ti wá, nipa ọdọ enia li ajinde
ninu okú si ti wá pẹlu.
22 Nitori bi gbogbo enia ti kú ninu
Adamu, bẽni gbogbo enia yio si di ãye ni-
nu Kristi.
23 Ṣugbọn olukuluku enia ni ipa tirẹ̀:
Kristi akọbi; lẹhin eyini awọn ti iṣe ti
Kristi li àbọ rẹ̀.
24 Nigbana li opin o de, nigbati o ba ti
fi ijọba fun Ọlọrun, ani Baba; nigbati o ba
ti tẹ̀ ori gbogbo awọn olori, ati gbogbo ọlá
ati agbara ba.
25 Nitoripe kò le ṣaima jọba, titi yio fi
tẹ̀ ori gbogbo awọn ọtá mọlẹ li atẹlẹsẹ rẹ̀.
26 Ikú ni ọtá ikẹhin ti a o parun.
27 Nitori o ti tẹ̀ ohun gbogbo mọlẹ li
atẹlẹsẹ rẹ̀. Ṣugbọn nigbati o wipe ohun
gbogbo li a fi sabẹ rẹ̀, o daniloju pe, on
nikanṣoṣo li o kù, ti o fi ohun gbogbo si i
labẹ.
28 Nigbati a ba si tẹ̀ ori ohun gbogbo
ba fun u tan, nigbana li Ọmọ tikararẹ̀ pẹlu
yio tẹriba fun ẹniti o fi ohun gbogbo sabẹ
rẹ̀, ki Ọlọrun ki o le jasi gbogbo li ohun
gbogbo.
29 Njẹ kili awọn ti a baptisi nitori okú
yio ha ṣe, bi o ba ṣepe awọn okú kò jinde
rara? nitori kili a ha ṣe mbaptisi wọn
nitori okú?
30 Nitori kili awa si ṣe mbẹ ninu ewu
ni wakati gbogbo?
31 Ayọ̀ nyin ti mo ni nipa Kristi Jesu
Oluwa wa ni mo fi sọ pe, emi nkú li ojo-
jumọ́.
32 Ki a wi nipa ti enia, bi mo ba ẹranko
jà li Efesu, anfani kili o jasi fun mi, bi o
ba ṣepe awọn okú kò jinde? ẹ jẹ ki a mã
jẹ, ẹ jẹ ki a mã mu; ọla li awa o sá kú.
33 Ki a má tàn nyin jẹ: ọ̀rọ buburu
ama bà ìwa rere jẹ.
34 Ẹ jí si ododo, ki ẹ má si dẹṣẹ mọ́;
nitori awọn ẹlomiran kò ni ìmọ Ọlọrun:
mo sọ eyi fun itiju nyin.
35 Ṣugbọn ẹlomiran yio wipe, Bawo li a
o ha jí awọn okú dide? ara bawo ni nwọn
o pada si?
36 Iwọ alaimoye, ohun ti iwọ fọnrugbin
ki ihù bikoṣepe o ba kú:
37 Ati eyi ti iwọ fọnrugbin, ara ti mbọ̀
ki iwọ fọnrugbin, ṣugbọn irugbin lasan ni,
ibã ṣe alikama, tabi irú miran.
38 Ṣugbọn Ọlọrun fun u li ara bi o ti
wù u, ati fun irú olukuluku ara tirẹ̀.
39 Gbogbo ara kì iṣe ẹran-ara kanna:
ṣugbọn ọ̀tọ li ẹran-ara ti enia, ọ̀tọ li ẹran-
ara ti ẹrankọ, ọ̀tọ ni ti ẹja, ọ̀tọ si ni ti ẹiyẹ.
40 Ara ti oke ọrun mbẹ, ara ti aiye pẹlu
si mbẹ: ṣugbọn ogo ti oke ọrun ọ̀tọ, ati
ogo ti aiye ọ̀tọ.
41 Ọ̀tọ li ogo ti õrùn, ọ̀tọ li ogo ti
oṣupa, ọ̀tọ si li ogo ti irawọ: irawọ sá yàtọ
si irawọ li ogo.
42 Gẹgẹ bẽ si li ajinde okú, A gbìn i ni
idibajẹ; a si jí i dide li aidibajẹ:
43 A gbìn i li ainiyìn; a si jí i dide li
ogo: a gbìn i li ailera, a si jí i dide li
agbara:
44 A gbìn i li ara iyara; a si jí i dide li
ara ẹmí. Ara iyara mbẹ, ara ẹmí si mbẹ.
45 Bẽli a si kọ ọ pe, Adamu iṣaju ọkọn-
rin alãye ọkàn li a da a; Adamu ikẹhin
ẹmí isọnidãye.
46 Ṣugbọn eyi ti iṣe ẹlẹmí kọ́ tète ṣaju,
bikoṣe eyi ti iṣe ara iyara; lẹhinna eyi ti
iṣe ẹlẹmí.
47 Ọkọnrin ti iṣaju ati inu erupẹ̀ wá,
ẹni erupẹ̀: ọkọnrin ekeji Oluwa lati ọrun
wá.
48 Bi ẹni erupẹ̀ ti ri, bẽ si ni irú awọn
ti iṣe ti erupẹ̀: bi ẹni ti ọrun ti ri, bẽ si ni
irú awọn ti iṣe ti ọrun.

Digitized by Google

49 Bi awa si ti rù aworan ẹni erupẹ̀, bẹ̃li
awa o si ru aworan ẹniti iṣe ti ọrun.
50 Ará, njẹ eyi ni mo wi fun nyin pe,
ara on ẹ̀jẹ kò le jogún ijọba Ọlọrun ; bẹ̃ni
idibajẹ kò le jogún aidibajẹ.
51 Kiyesi i, ohun ijinlẹ ni mo fihàn
nyin ; Gbogbo wa kì yio sùn, ṣugbọn gbo-
gbo wa li a o palarada,
52 Lọgan, ni iṣẹ́ju, nigba ipè ikẹhin :
nitori ipè o dún, a o si jí awọn okú dide li
aidibajẹ, a o si pawalara dà.
53 Nitoripe ara idibajẹ yi yio mu aidi-
bajẹ wọ̀, ati ara ikú yi yio mu aikú wọ̀.
54 Bẹ̃ni nigbati ara idibajẹ yi ba ti mu
aidibajẹ wọ̀, ati ara ikú yi ba si ti mu aikú
wọ̀ bẹ̃ tan, nigbana li ọrọ ti a kọ yio ṣẹ
pe, A gbé ikú mì ni iṣẹgun.
55 Ikú, oró rẹ dà ? Isà okú, iṣẹgun rẹ
dà ?
56 Oró ikú li ẹ̀ṣẹ ; ati agbara ẹ̀ṣẹ li ofin.
57 Ṣugbọn ọpẹ́ ni fun Ọlọrun ẹniti o ti
fun wa ni iṣẹgun nipa Jesu Kristi Oluwa
wa.
58 Nitorina ẹnyin ará mi olufẹ, ẹ mã
duro ṣinṣin, laiyẹsẹ, ki ẹ mã pọ̀ si i ni iṣẹ
Oluwa nigbagbogbo, niwọn bi ẹnyin ti mọ̀
pe iṣẹ nyin kì yio jasi asan nipa ti Oluwa.

## ORI 16.

NJẸ niti idawo fun awọn enia mimọ́, bi
mo ti fi aṣẹ fun gbogbo ijọ Galatia,
gẹgẹ bẹ̃ni ki ẹ ṣe.
2 Li ọjọ ikini ọ̀sẹ, ki olukuluku nyin fi
sinu iṣura lọdọ ara rẹ̀ li apakan, gẹgẹ bi
Ọlọrun ti ṣe rere fun u, ki o máṣe si ikojọ
nigbati mo ba de.
3 Ati nigbati mo ba de, ẹnikẹni ti o ba
ṣe ẹni itẹwọgbà nipa iwe nyin, awọn li
emi o rán lati mu ẹ̀bun nyin gòke lọ si
Jerusalemu.
4 Bi o ba si yẹ ki emi ki o lọ pẹlu, nwọn
o si ba mi lọ.
5 Emi o tọ̀ nyin wá nisisiyi, nigbati emi
o kọja lọ larin Makedonia : nitoriti emi
nkọja lọ larin Makedonia.
6 Bọya emi o si duro, ani, emi a si
potutù pẹlu nyin, ki ẹnyin ki o le sìn mi
li ọ̀na àjo mi, nibikibi ti mo gbé nlọ.
7 Nitori emi kì yio ri nyin li ọ̀na nisi-
siyi ; ṣugbọn emi gbẹkẹle lati duro lọdọ
nyin nigba diẹ, bi Oluwa ba fẹ.
8 Ṣugbọn emi o duro ni Efesu titi di
Pentekosti.
9 Nitoripe ilẹkun nla ati aitase ṣí silẹ
fun mi, ọ̀pọlọpọ si li awọn ọtá ti mbẹ.
10 Njẹ bi Timoteu ba de, ẹ kiyesi ki o
le wà lọdọ nyin laibẹ̀ru : nitoriti on nṣe iṣẹ
Oluwa, gẹgẹ bi emi ti nṣe.
11 Nitorina ki ẹnikẹni máṣe kẹgan rẹ̀ :
ṣugbọn ki ẹ sìn i jade li alafia, ki on ki o
le tọ̀ mi wá : nitoriti emi nwò ọ̀na rẹ̀ pẹlu
awọn arakọnrin.
12 Nipa ti Apollo arakọnrin wa, mo fẹ
gidigidi ki o tọ̀ nyin wá pẹlu awọn ara-
kọnrin : ṣugbọn kì iṣe ifẹ rẹ̀ lati wá nisi-
siyi : ṣugbọn on o wá nigbati o ba ni
akokò ti o wọ̀.
13 Ẹ mã ṣọra, ẹ duro gangan ni igba-
gbọ́, ẹ ṣe ara nyin bi ọkọnrin, ki ẹ si jẹ
alagbara.
14 Ẹ mã fi ifẹni ṣe gbogbo nkan nyin.
15 Mo bẹ̀ nyin, ará, (ẹ sá mọ̀ ile ti
Stefana, pe awọn li akọso ti Akaia, ati
pe, nwọn si ti fi ara fun iṣẹ iranṣẹ fun
awọn enia mimọ́,)
16 Ki ẹnyin ki o tẹriba fun irú awọn
bawọnni, ati fun olukuluku ẹniti nṣe iran-
lọwọ pẹlu wa, ti o si nṣiṣẹ.
17 Mo yọ̀ nitori wíwa Stefana ati Fortu-
natu ati Akaiku : nitori eyi ti o kù nipa
ti nyin nwọn ti fi kún u.
18 Nitoriti nwọn tù ẹmí mi lara ati ti
nyin : nitorina ẹ mã jẹwọ irú awọn ti o
ri bẹ̃.
19 Ijọ ni Asia kí nyin. Akuila ati
Priskilla, kí nyin gidigidi niti Oluwa, pẹlu
ijọ ti o wà ni ile wọn.
20 Gbogbo awọn arakọnrin kí nyin. Ẹ
fi ifẹnukonu mimọ́ kí ara nyin.
21 Ikíni ti emi Paulu, lati ọwọ́ emi
tikarami wá.
22 Bi ẹnikẹni kò ba fẹ Jesu Kristi Olu-
wa, ẹ jẹ ki o di Anatema Maran-ata (ẹni
ègun).
23 Ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa ki o
wà pẹlu nyin.
24 Ifẹ mi wà pẹlu gbogbo nyin ninu
Kristi Jesu. Amin.

A kọ Episteli ikini si awọn ara Ko-
rinti, lati Filippi lọ, lati ọwọ́ Ste-
fana, ati Fortunatu, ati Akaiku, ati
Timoteu.

Digitized by Google

EPISTELI KEJI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA KORINTI.

## ORI 1.

PAULU Aposteli Jesu Kristi nipa ifẹ Ọlọrun, ati Timoteu arakọnrin wa, si ijọ enia Ọlọrun ti o wà ni Korinti, pẹlu gbogbo ijọ enia mimọ́ ti o wà ni gbogbo Akaia:

2 Ore-ọfẹ si nyin, ati alafia lati ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati Jesu Kristi Oluwa.

3 Olubukún li Ọlọrun, ani Baba Jesu Kristi Oluwa wa, Baba iyọ́nu, ati Ọlọrun itunu gbogbo;

4 Ẹniti ntù wa ninu ni gbogbo wahalà wa, nipa itunu na ki awa ki o le mã tù awọn ti o wà ninu wahalà-kiwahalà ni inu, nipa eyiti a fi ntù awa tikarawa ninu lati ọdọ Ọlọrun wá.

5 Nitoripe bi ìya Kristi ti di pipọ ninu wa, gẹgẹ bẹ̃ni itunu wa di pipọ pẹlu nipa Kristi.

6 Bi a ba si npọ́n wa loju ni, o jasi itunu ati igbala nyin, eyiti a ṣe daju nipa ifaiyarán ìya na ti awa njẹ pẹlu: tabi bi a ba ntù wa ninu, o jasi fun itunu ati igbala nyin.

7 Ati ireti wa nipa ti nyin duro ṣinṣin, awa mọ̀ pe, bi ẹnyin ti jẹ alabapin ninu ìya, bẹ̃li ẹnyin o si jẹ pẹlu ninu itunu na.

8 Ará, awa kò sá fẹ ki ẹnyin ki o wà li aimọ̀ nipa wahalà wa, ti o de si wa ni Asia, niti a pọ́n wa loju lọpọlọpọ, rekọja agbara wa, ani tobẹ̃ ti ireti kò si fun ẹmi wa mọ́:

9 Ṣugbọn awa ni idahùn ikú ninu ara wa, ki awa ki o máṣe gbẹkẹle ara wa, bikoṣe Ọlọrun ti njí okú dide:

10 Ẹniti o ti gbà wa kuro ninu ikú ti o tobi tobẹ̃, ti o si ngbà wa: ẹniti awa gbẹkẹle pe, yio si tún mã gbà wa;

11 Ẹnyin pẹlu nṣe iranlọwọ nipa adura nyin fun wa, pe nitori ẹ̀bun ti a fifun wa nipasẹ ọ̀pọlọpọ enia, ki ọ̀pọlọpọ ki o le ma dupẹ nitori wa.

12 Nitori eyi ni iṣogo wa, ẹrí ọkàn wa, pe, li ọkàn kan ati otitọ ti Ọlọrun, kì iṣe nipa ọgbọ́n ara, bikoṣe nipa ore-ọfẹ Ọlọrun, li awa nhuwa li aiye, ati si nyin li ọ̀pọlọpọ.

13 Nitoripe awa kò kọwe ohun miran si nyin jù eyi ti ẹnyin kà lọ, tabi ti ẹnyin jẹwọ: mo si gbẹkẹle pe ẹnyin o jẹwọ titi di opin;

14 Gẹgẹ bi ẹnyin si ti jẹwọ wa pẹlu li apakan pe, awa li ayọ̀ nyin, gẹgẹ bi ẹnyin ti ṣe ayọ̀ wa pẹlu li ọjọ Jesu Oluwa.

15 Ninu igbẹkẹle yi ni mo ti ngbèro lati tọ̀ nyin wá niṣaju, ki ẹnyin ki o le ni ore-ọfẹ nigbakeji;

16 Ati lati kọja lọdọ nyin lọ si Makedonia, ati lati tún jade lati Makedonia wá sọdọ nyin, ati lati mu mi lati ọdọ nyin lọ si ìha Judea.

17 Nitorina nigbati emi ngbèro bẹ̃ ninu mi, emi ha fi ọwọ dẹrẹ mu u bi? tabi ohun wọnni ti mo pinnu, mo ha pinnu wọn gẹgẹ bi ti ara bi pe, ti yio fi jẹ bẹ̃ni bẹ̃ni, ati bẹ̃kọ bẹ̃kọ lọdọ mi?

18 Ṣugbọn bi Ọlọrun ti ṣe otitọ, ọ̀rọ wa fun nyin kì iṣe bẹ̃ni ati bẹ̃kọ.

19 Nitoripe Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun, ẹniti a ti wasu rẹ̀ larin nyin nipasẹ wa, ani nipasẹ emi ati Silfanu ati Timoteu, kì iṣe bẹ̃ni ati bẹ̃kọ, ṣugbọn ninu rẹ̀ ni bẹ̃ni.

20 Nitoripe ninu rẹ̀ ni gbogbo ileri Ọlọrun jẹ bẹ̃ni, ati ninu rẹ̀ Amin, si ogo Ọlọrun nipasẹ wa.

21 Njẹ nisisiyi, Ọlọrun ni, ẹniti o fi ẹsẹ wa mulẹ pẹlu nyin ninu Kristi, ti o si fi àmi oróro yàn wa;

22 Ẹniti o si ti ṣe èdidi wa pẹlu, ti o si ti fi akọso eso Ẹmi si wa li àiya.

23 Pẹlupẹlu mo pè Ọlọrun ṣe ẹlẹri li ọkàn mi pe, nitori lati dá nyin si li emi kò ṣe ti wá si Korinti di isisiyi.

24 Kì iṣe nitori ti awa li agbara lori igbagbọ́ nyin, ṣugbọn awa ni iṣe oluran-

Digitized by Google

lọwọ ayọ̀ nyin: nitoripe ẹnyin duro nipa
igbagbọ́.

## ORI 2.

SUGBỌN mo ti pinnu eyi ninu emi tika-
rami pe, emi kì yio tun fi ibinujẹ tọ̀
nyin wá.
2 Nitoripe bi emi ba mu inu nyin bajẹ,
njẹ ta li ẹniti o si nmu inu mi dùn, bikoṣe
ẹniti mo ti bà ninu jẹ?
3 Emi si kọwe nitori eyi kanna si nyin
pe, nigbati mo ba si de, ki emi ki o máṣe
ni ibinujẹ lọdọ wọn, nitori awọn ti emi
iba mã yọ̀: nitoriti mo ni igbẹkẹle ninu
gbogbo nyin, nitori ayọ̀ mi li ayọ̀ fun gbo-
gbo nyin.
4 Nitoripe ninu ọ̀pọlọpọ wahalà ati àro-
kan li àiya mi ni mo ti fi ọ̀pọlọpọ omije
kọwe si nyin; kì iṣe nitori ki a le bà nyin
ninu jẹ, ṣugbọn ki ẹnyin ki o le mọ̀ ifẹ ti
mo ni si nyin gidigidi lọpọlọpọ.
5 Ṣugbọn bi ẹnikẹni ba mu ibinujẹ wá,
on kò bà mi ninu jẹ, bikoṣe niwọntunwọn-
si: ki emi ki o máṣe kà a si gbogbo nyin
lọrùn.
6 Iya yi ti ọpọlọpọ ti fi jẹ iru enia bẽ, o
to fun u.
7 Li eyiti o lodi, ẹnyin iba kuku dariji
i, ki ẹ si tù u ninu, boya ki àiya irú enia bẽ
ki o máṣe bò mọlẹ nipasẹ ọ̀pọlọpọ ibinujẹ.
8 Nitorina mo bẹ̀ nyin ki ẹnyin ki o le
fi ẹsẹ ifẹ nyin mulẹ si oluwarẹ̀.
9 Nitori eyi na pẹlu ni mo ti kọwe, ki
emi ki o le mọ̀ nyin dajudaju, bi ẹnyin ba
ṣe eletí ọmọ li ohun gbogbo.
10 Ẹniti ẹnyin ba si fi ohunkohun jì
fun, mo si fi jì pẹlu: nitoripe bi emi ba
fi ohunkohun jì, ẹniti mo ba fi jì fun,
nitori ti nyin ni mo ṣe fi i jì niwaju
Kristi;
11 Ki ọwọ́ Satani ki o máṣe tẹ̀ anfani
wa: nitori awa kò ṣe alaimọ̀ arekereke
rẹ̀.
12 Pẹlupẹlu nigbati mo de Troa lati
wasu ihin-rere Kristi, ti ilẹkun si ṣí silọ
fun mi lati ọdọ Oluwa wá,
13 Emi kò ni alafia li ọkàn mi, nitori ti
emi ko ri Titu arakọnrin mi: ṣugbọn ni-
gbati mo ti ba wọn dagbere, mo ti ibẹ̀ kọja
lọ si Makedonia.
14 Ọpẹ́ ni fun Ọlọrun nisisiyi, ẹniti nmu
wa bori nigbagbogbo ninu Kristi, ti o si
nfi õrùn didùn ìmọ rẹ̀ hàn nipa wa nibi
gbogbo.
15 Nitoripe õrùn didùn Kristi li awa
jasi fun Ọlọrun, si awọn ti a gbalà, ati si
awọn ti o ṣegbé:
16 Awa jasi õrùn ikú si ikú fun ẹnikan;
ati õrùn ìye si ìye fun ẹnikeji. Tali ẹniti
o ha si to fun nkan wọnyi?
17 Nitori ti awa kò dabi awọn ọ̀pọlọpọ,
ti nfi ọ̀rọ Ọlọrun ṣiṣẹ ẹ̀tan: ṣugbọn bi
nipa otitọ inu, ṣugbọn bi lati ọdọ Ọlọrun
wá, ati niwaju Ọlọrun li awa nsọ̀rọ ninu
Kristi.

## ORI 3.

AWA ha tún bẹ̀rẹ lati ma yìn ara wa bi?
tabi awa ha nfẹ iwe iyìn sọdọ nyin,
tabi lati ọdọ nyin bi awọn ẹlomiran?
2 Ẹnyin ni iwe wa, ti a ti kọ si wa
li àiya, ti gbogbo enia ti mọ̀, ti nwọn si
ti kà.
3 Niwọn bi a ti fi nyin hàn nigbangba
pe, iwe Kristi ni nyin, ti awa nṣe iranṣẹ
fun, kì iṣe eyiti a fi tadawa kọ, ṣugbọn Ẹmí
Ọlọrun alãye; ti kì iṣe ninu tabili okuta,
bikoṣe ninu tabili ẹran-ara àiya.
4 Irú igbẹkẹle yi li awa ni nipa Kristi
sọdọ Ọlọrun:
5 Kì iṣe pe awa to fun ara wa lati ṣirò
ohunkohun bi ẹnipe ti awa tikarawa; ṣu-
gbọn Ọlọrun ni tito wa;
6 Ẹniti o mu wa tó bi iranṣẹ majẹmu
titun; kì iṣe ti iwe, bikoṣe ti ẹmí: nitori
ti iwe ama pani, ṣugbọn ẹmí ama sọni di
ãye.
7 Ṣugbọn bi iṣẹ iranṣẹ ti ikú, ti a ti
kọwe rẹ̀, ti a si ti ṣe ọnà finfin rẹ̀ si ara
okuta, ba jẹ ologo, tobẽ ti awọn ọmọ Isra-
eli kò le tẹjumọ ati wò oju Mose, nitori ogo
oju rẹ̀; ogo ti a o sọ di asan:
8 Yio ha ti ri ti iṣẹ iranṣẹ ti ẹmí kì yio
kuku jẹ ologo julọ?
9 Nitoripe bi iṣẹ iranṣẹ fun idalẹbi ba jẹ
ologo, melomelo ni iṣẹ iranṣẹ ododo yio
rekọja li ogo.
10 Nitori eyi ti a tilẹ ṣe logo, kò li
ogo mọ́ nitori eyi, nipasẹ ogo ti o tayọ
julọ.
11 Nitoripe bi eyi ti o ti ti ọ̀na kuro ba
logo, melomelo li eyi ti o duro yio logo.
12 Njẹ nitorina bi awa ti ni irú ireti bẽ,
awa nfi igboiya sọ̀rọ:
13 Kì iṣe bi Mose, ẹniti o fi iboju kan si
oju rẹ̀, ti awọn ọmọ Israeli kò le tẹjumọ
wò eyiti a mu kuro titi de opin:
14 Ṣugbọn oju inu wọn fọ́: nitoripe titi
fi di oni oloni, iboju na wà li aimu kuro ni
kikà iwe majẹmu atijọ; iboju ti a ti mu
kuro ninu Kristi.

Digitized by Google

15 Ṣugbọn titi di oni oloni, nigbati a ba
nkà Mose, iboju na mbẹ li àiya wọn.
16 Ṣugbọn nigbati on o ba yipada si
Oluwa, a o mu iboju na kuro.
17 Ṣugbọn Oluwa li Ẹmí nì: nibiti Ẹmí
Oluwa ba si wà, nibẹ̀ li omnira gbé wà.
18 Ṣugbọn gbogbo wa, nwò ogo Oluwa
laisi iboju bi ẹnipe ninu awojiji, a si npa-
wada si aworan kanna lati ogo de ogo, ani
bi lati ọdọ Ẹmí Oluwa.

## ORI 4.

NITORINA bi awa ti ni iṣẹ iranṣẹ yi,
gẹgẹ bi a ti ri ãnu gbà, ãrẹ̀ kò mu
wa;
2 Ṣugbọn awa ti kọ̀ gbogbo ohun ìkọkọ
ti o ni itiju silẹ, awa kò rìn li ẹ̀tan, bẹ̃li
awa kò fi ọwọ́ ẹ̀tan mu ọ̀rọ Ọlọrun; ṣugbọn
nipa fifi otitọ hàn, awa nyìn ara wa si ọkàn
olukuluku enia niwaju Ọlọrun.
3 Ṣugbọn bi ihin-rere wa ba farasin, o
farasin fun awọn ti o nù:
4 Ninu awọn ẹniti ọlọrun aiye yi ti
sọ ọkàn awọn ti kò gbagbọ́ di afọju, ki
imọlẹ ihin-rere Kristi ti o logo, ẹniti iṣe
aworan Ọlọrun, ki o máṣe mọlẹ ninu wọn.
5 Nitori awa kò wasu awa tikarawa, bi-
koṣe Kristi Jesu Oluwa; awa tikarawa si
jasi ẹrú nyin nitori Jesu.
6 Nitori Ọlọrun, ẹniti o paṣẹ ki imọlẹ
ki o mọlẹ lati inu òkunkun jade, on li o ti
nmọlẹ li àiya wa, lati fun wa ni imọlẹ ìmọ
ogo Ọlọrun li oju Jesu Kristi.
7 Ṣugbọn awa ni iṣura yi ninu ohunèlo
amọ̀, ki ọlánla agbara na ki o le ṣe ti Ọlọ-
run, ki o má si ṣe jẹ ti wa.
8 Nitorina a nwahalà wa niha gbogbo,
ṣugbọn awa kò binujẹ: a ndamu wa, ṣu-
gbọn awa kò ṣe alaireti;
9 A nṣe inunibini si wa, ṣugbọn a kò kọ̀
wa silẹ; a nrẹ̀ wa silẹ, ṣugbọn a kò si pa
wa run;
10 Awa nrẹrù ikú Jesu Oluwa kiri li ara
wa nigbagbogbo, ki a le fi ìye Jesu hàn
pẹlu li ara wa.
11 Nitoripe nigbagbogbo li a nfi awa ti
o wà lãyè fun ikú nitori Jesu, ki a le fi ìye
Jesu hàn ninu ara okú wa pẹlu.
12 Bẹ̃ni ikú nṣiṣẹ ninu wa, ṣugbọn ìye
ninu nyin.
13 Awa li ẹmí igbagbọ́ kanna, gẹgẹ bi a
ti kọ́ ọ pe, emi gbagbọ́, nitorina li emi si ti
ṣe sọ: awa pẹlu gbagbọ́, nitorina li awa si
ṣe nsọ;
14 Awa mọ̀ pe, ẹniti o jí Jesu Oluwa
dide yio si jí wa dide pẹlu nipa Jesu, yio si
fi wa hàn pẹlu nyin.
15 Nitoripe ti nyin li ohun gbogbo jasi,
ki ọ̀pọlọpọ ore-ọfẹ nipa idupẹ awọn ẹni
pupọ̀, ki o le jasi ogo Ọlọrun lọpọlọpọ.
16 Nitori eyi ni ãrẹ̀ kò ṣe mu wa; ṣu-
gbọn bi ọkọnrin ti ode wa ba nparun, sibẹ
ọkọnrin ti inu wa ndi titun li ojojumọ́.
17 Nitori ipọnju wa ti o fẹrẹ, eyiti iṣe
ìwọn igba iṣẹ́ju kan, o nṣiṣẹ ogo ainipẹkun
ti o pọ̀ rekọja.
18 Niwọn bi awa kò ti wò ohun ti a nri,
bikoṣe ohun ti awa kò ri: nitoripe ohun ti
a nri ni ti igba isisiyi; ṣugbọn ohun ti a
kò ri ni ti aiyeraiye.

## ORI 5.

NITORI awa mọ̀ pe, bi ile erupẹ̀ agọ́ wa
yi ba di yíyọ, awa ni ile kan lati ọdọ
Ọlọrun, ile ti a kò fi ọwọ́ kọ́, ataiyeraiye
ninu awọn ọrun.
2 Nitori awa nkerora ninu eyi, awa si
nfẹ gidigidi lati fi ile wa lati ọrun wá wọ̀
wa:
3 Bi o ba ṣepe a ti wọ̀ wa li aṣọ, a kì yio
bá wa ni ìhoho.
4 Nitori awa ti o wà ninu agọ́ yi nkero-
ra, ẹrù npa wa: kì iṣe nitori ti awa nfẹ ijẹ
alaiwọ̀ṣọ, ṣugbọn ki a le wọ̀ wa li aṣọ, ki
iyè ki o le gbe iku mi.
5 Ṣugbọn ẹniti o ṣe wa fun nkan yi ni
Ọlọrun, ẹniti o si ti fi akọso Ẹmí fun wa
pẹlu.
6 Nitorina awa ni igboiya nigbagbogbo,
awa si mọ̀ pe, nigbati awa mbẹ ni ile ara,
awa kò si lọdọ Oluwa:
7 (Nitoripe nipa igbagbọ́ li awa nrìn, kì
iṣe nipa riri:)
8 Mo ni, awa ni igboiya, awa si nfẹ ki a
kuku ti inu ara kuro, ki a si le wà lọdọ
Oluwa.
9 Nitorina awa nṣe aisimi, pe bi awa ba
wà tabi bi a kò si, ki awa ki o le jẹ ẹni itẹ-
wọgbà lọdọ rẹ̀.
10 Nitoripe gbogbo wa kò le ṣaima fi ara
hàn niwaju itẹ́ idajọ Kristi; ki olukuluku
ki o le gbà nkan wọnni ti o ti ṣe li ara rẹ̀,
gẹgẹ bi eyi ti o ti ṣe, ibã ṣe rere ibã ṣe bu-
buru.
11 Nitorina bi awa ti mọ̀ ẹ̀ru nla Oluwa,
awa nyi enia li ọkàn pada; ṣugbọn a nfi
wa hàn fun Ọlọrun; mo si gbagbọ́ pe, a si
fi wa hàn li ọkàn nyin pẹlu.
12 Nitori awa kò si ni tún ma yìn ara
wa si nyin mọ́, ṣugbọn awa fi àye fun nyin
lati mã ṣogo nitori wa, ki ẹ le ni ohun ti

Digitized by Google

ẹnyin o fi da wọn lohùn, awọn ti nṣogo li
oju, ki isi iṣe li aiya.
13 Nitorina bi ori wa ba bajẹ, o bajẹ
fun Ọlọrun: tabi bi awa ba ṣe airekọja, a
ṣe airekọja nitori ti nyin.
14 Nitori ifẹ Kristi nrọ̀ wa; nitori awa
rò bayi, pe bi ẹnikan ba ti kú fun gbogbo
enia, njẹ gbogbo wọn li o kú:
15 Ati pe o ti kú fun gbogbo wọn, ki
awọn ẹniti o wà lãye ki o má si ṣe wà lãye
fun ara wọn mọ́ lati isisiyi lọ, bikoṣe fun
ẹniti o ti kú fun wọn, ti o si jinde.
16 Nitorina lati isisiyi lọ awa kò mọ̀
ẹnikan nipa ti ara mọ́; nitõtọ, bi awa tilẹ
ti mọ̀ Kristi ri nipa ti ara, ṣugbọn lati
isisiyi lọ, awa kò mọ̀ ọ mọ́.
17 Nitorina bi ẹnikẹni ba wà ninu
Kristi, o di ẹda titun: gbogbo ohun atijọ
ti kọja lọ; kiyesi i, ohun gbogbo si di
titun.
18 Ohun gbogbo si ni ti Ọlọrun, ẹniti o
si ti ba wa làja si ara rẹ̀ nipasẹ Jesu Kristi,
ti o si ti fi iṣẹ alufa ìlaja fun wa;
19 Eyini ni pe, Ọlọrun wà ninu Kristi,
o mba araiye làja si ara rẹ̀, kò si kà ẹ̀ṣẹ wọn
si wọn lọrùn; o si ti fi ọ̀rọ ìlaja le wa
lọwọ.
20 Njẹ nisisiyi awa ni ikọ̀ fun Kristi,
gẹgẹ bi ẹnipe Ọlọrun nti ọdọ wa bẹ̀ nyin:
awa mbẹ̀ nyin nipò Kristi, ki ẹnyin ki o
ba Ọlọrun làja.
21 Nitori o ti fi i ṣe ẹ̀ṣẹ nitori wa, ẹniti
kò mọ̀ ẹ̀ṣẹkẹṣẹ ri; ki a le fi wa ṣe ododo
Ọlọrun ninu rẹ̀.

## ORI 6.

NITORINA awa, bi alabaṣe pọ̀ pẹlu rẹ̀,
awa mbẹ̀ nyin pẹlu ki ẹnyin ki o máṣe
gbà ore-ọfẹ Ọlọrun lasan.
2 (Nitori o wipe, emi ti gbohùn rẹ li
akokò kan itẹwọgbà, ati li ọjọ igbala ni
mo si ti ràn ọ lọwọ: kiyesi i, nisisiyi ni
akokò itẹwọgbà; kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ
igbala.)
3 Awa kò si fi ohun idugbolu kan si ọna
ẹnikẹni, ki iṣẹ alufa ki o máṣe di isọrọ bu-
buru si:
4 Ṣugbọn li ohun gbogbo awa nyìn ara
wa bi awọn iranṣẹ Ọlọrun, ninu ọ̀pọlọpọ
sũru, ninu ipọnju, ninu aini, ninu wahalà
pipọ,
5 Nipa ìna, ninu tubu, nipa ìti soke tì
sodo pipọ, nipa ìṣẹ́, nipa iṣọra, nipa igbawẹ
pipọ;
6 Nipa ìwa mimọ́, nipa ìmọ, nipa ipamọ-
ra, nipa iṣeun, nipa Ẹmi Mimọ́, nipa ifẹ
aiṣẹtan,
7 Nipa ọ̀rọ otitọ, nipa agbara Ọlọrun,
nipa ihamọra ododo li apa ọtún ati li apa
òsi,
8 Nipa ọlá ati ẹ̀gan, nipa ìhin buburu
ati ìhin rere: bi ẹlẹtan, ṣugbọn a jasi
olõtọ:
9 Bi ẹniti a kò mọ̀, ṣugbọn a ti di mimọ̀
dajudaju; bi ẹniti nkú lọ, si kiyesi i, awa
wà lãye; bi ẹniti a n-nà, ki si iṣe ti pipa;
10 Bi ẹniti o kún fun ibinujẹ, ṣugbọn
awa nyọ̀ nigbagbogbo; bi talakà, ṣugbọn
awa nsọ ọ̀pọlọpọ di ọlọrọ̀; bi ẹniti kò ni
nkan, ṣugbọn awa si ni ini ohun gbogbo.
11 Ẹnyin ara Korinti, ẹnu wa yà si
nyin, àiya wa ṣi silẹ si nyin.
12 A kò ni nyin lara nitori wa, ṣugbọn
a n-ni nyin lara nitori ikùn ẹnyin tikara
nyin.
13 Njẹ niti ẹsan kan bi bẽ̀ gẹgẹ, (emi
nsọ bi ẹnipe fun awọn ọmọ mi,) ki ẹnyin
di pipọ pẹlu.
14 Ẹ máṣe fi aidọgba dàpọ pẹlu awọn
alaigbagbọ́: nitori ìdapọ kili ododo ni pẹlu
aiṣododo? ìdapọ kini imọlẹ si ni pẹlu
òkunkun?
15 Irẹpọ̀ kini Kristi ni pẹlu Beliali?
tabi ipa wo li ẹniti o gbagbọ́ ni pẹlu alai-
gbàgbọ?
16 Irẹpọ̀ kini tempili Ọlọrun ni pẹlu
oriṣa? nitori ẹnyin ni tempili Ọlọrun alã-
ye; gẹgẹ bi Ọlọrun ti wipe, Emi o ma gbé
inu wọn, emi o si ma rìn ninu wọn; emi o
si jẹ Ọlọrun wọn, nwọn o si jẹ enia mi.
17 Nitorina ẹ jade kuro larin wọn, ki ẹ
si yà ara nyin si ọ̀tọ, li Oluwa wi, ki ẹ
máṣe fi ọwọ́ kàn ohun aimọ́; emi o si gbà
nyin.
18 Emi o si jẹ Baba fun nyin, ẹnyin o si
jẹ ọmọkọnrin mi ati ọmọbirin mi, li Oluwa
Olodumare wi.

## ORI 7.

BI awa ti ni ileri wọnyi, olufẹ ọwọn, ni-
torina ẹ jẹ ki a wẹ̀ ara wa mọ́ kuro
ninu gbogbo ẹgbin ti ara ati ti ẹmí, ki a jẹ
pipé ninu ìwa mimọ́ ni ìbẹru Ọlọrun.
2 Ẹ gbà wa; nitori awa kò fi ibi ṣe ẹni-
kẹni, awa kò bà ẹnikẹni jẹ, awa kò rẹ́ ẹni-
kẹni jẹ.
3 Emi kò sọ eyi bayi lati da nyin lẹbi:
nitori mo ti wi ṣaju pe, ifẹ wa si nyin li
àiya wa ni, lati kú ati lati wà lãye pẹlu
nyin.
4 Mo ni igboiya nla si nyin lati sọ̀rọ, mo

li ohùn nla lati ṣogo nitori nyin: mo si
kún fun itunu, mo si nyọ̀ gidigidi ninu
gbogbo ipọnju wa.
5 Nitoripe nigbati awa de Makedonia,
ara wa kò balẹ, ṣugbọn a nwahalà wa niha
gbogbo; ìja mbẹ lode, ẹ̀ru mbẹ ninu.
6 Ṣugbọn Ọlọrun, ẹniti ntù awọn ti a rẹ̀
silẹ ninu, o tù wa ninu nipasẹ wíwa Titu;
7 Kì si iṣe nipa wíwa rẹ̀ nikan, ṣugbọn
nipa itunu na ti a ti tù u ninu nipasẹ nyin,
nigbati o sọ ifẹ nyin ti o gbona fun wa,
ẹkún nyin, itara inu nyin si mi; bẹ̃ni mo
si yọ̀ rekọja.
8 Nitoripe bi mo tilẹ fi iwe mu inu nyin
bajẹ, emi kò kãnu mọ́, bi mo tilẹ ti kãnu
ri: nitori ti mo woye pe iwe kanna mu
nyin binujẹ, bi o tilẹ dabi ẹnipe fun igba
akokò kan ni.
9 Emi yọ̀ nisisiyi, kì iṣe nitoriti a mu
inu nyin bajẹ, ṣugbọn nitori ti ẹnyin bi-
nujẹ si ironupiwada: nitoriti a mu inu
nyin bajẹ gẹgẹ bi ẹni ìwa-bi-Ọlọrun, ki
ẹnyin ki o máṣe padanù li ohunkohun
nipasẹ wa.
10 Nitoripe ibanujẹ ẹni ìwa-bi-Ọlọrun
ama ṣiṣẹ ironupiwada si igbala ti a kì iro-
nupiwada rẹ̀: ṣugbọn ibanujẹ ti aiye ama
ṣiṣẹ ikú.
11 Kiyesi i, nitori ohun kanna yi, ti
ẹnyin ti binujẹ gẹgẹ bi ti ẹni ìwa-bi-Ọlọ-
run, aniyan ti o mu nyin ṣe ti pọ̀ to, ani
ẹnyin ti wẹ̀ ara nyin mọ́ to, ani ibinu, ani
ìbẹru, ani ifẹ gbigbona, ani itara, ani
igbẹsan! Ninu ohun gbogbo ẹnyin ti ṣe
ara nyin daju lati wẹ̀ ara nyin mọ́ ninu
ọ̀ran yi.
12 Nitorina, bi mo tilẹ kọwe si nyin,
emi kò kọ ọ nitori ẹniti o ṣe ohun buburu
na, tabi nitori ẹniti a fi ohun buburu na ṣe,
ṣugbọn ki aniyan wa nitori nyin niwaju
Ọlọrun ki o le fi ara hàn nyin.
13 Nitorina a ti tù wa ninu nipa itunu
nyin: ani awa si yọ̀ gidigidi nipa ayọ̀ Titu,
nitori ti a ti tù ẹmí rẹ̀ lara nipa gbogbo
nyin.
14 Bi mo tilẹ ti ṣe ileri ohunkohun fun
u nitori nyin, oju kò tì mi; ṣugbọn gẹgẹ
bi awa ti sọ ohun gbogbo fun nyin li otitọ,
gẹgẹ bẹ̃li a si ri ileri wa, ti awa ṣe niwaju
Titu, si jasi otitọ.
15 Ifẹ inu rẹ̀ si ti di pupọ̀ gidigidi si
nyin, niwọn bi on ti nranti igbagbọ́ gbo-
gbo nyin, bi ẹnyin ti fi ìbẹru ati iwariri
tẹwọgbà a.
16 Nitorina mo yọ̀ nitoriti mo ni igbẹ-
kẹle ninu nyin li ohun gbogbo.

## ORI 8.

PẸLUPẸLU, ará, awa nsọ fun nyin niti
ore-ọfẹ Ọlọrun, ti a fifun gbogbo ijọ
Makedonia;
2 Bi o ti jẹ pe ninu idanwò ipọnju nla,
ọ̀pọlọpọ ayọ̀ wọn ati ibu aini wọn di pipọ
si ọrọ̀ iyọ́nu wọn.
3 Nitori mo jẹri si agbara wọn, ati jù
agbara wọn lọ, ifẹ inu awọn tikara wọn ni;
4 Nwọn nfi ẹ̀bẹ pipọ rọ̀ wa ki awa ki o
gbà ẹ̀bun na, ki awa ki o si gbà iṣẹ ìdapọ
ipinfunni si awọn enia mimọ́ na fun ara wa.
5 Eyi ni nwọn si ti ṣe, kì iṣe bi awa ti
gbèro, ṣugbọn nwọn tèteko fi awọn tikara
wọn fun Oluwa, ati fun wa, nipa ifẹ
Ọlọrun.
6 Tobẹ̃ ti awa fi bẹ̀ Titu pe, bi on ti
bẹ̀rẹ si, bẹ̃ni ki on ki o si pari ore-ọfẹ yi
ninu nyin pẹlu.
7 Nitorina bi ẹnyin ti pọ̀ li ohun gbo-
gbo, ni igbagbọ́, ati ọ̀rọ, ati ìmọ, ati ninu
aisimi gbogbo, ati nipa ifẹ nyin si wa, ẹ
kiyesi ki ẹnyin ki o si pọ̀ ninu ore-ọfẹ yi
pẹlu.
8 Kì iṣe nipa ofin ni mo fi nsọ, ṣugbọn
nipa ãpọn awọn ẹlomiran, ati lati ri idi
otitọ ifẹ inu nyin.
9 Nitori ẹnyin mọ̀ ore-ọfẹ Jesu Kristi
Oluwa wa, pe bi on ti jẹ ọlọrọ̀ ri, ṣugbọn
nitori nyin li o fi di alaini, ki a le sọ nyin
di ọlọrọ̀ nipa aini rẹ̀.
10 Ati ninu eyi ni mo fi ìmọ mi fun
nyin: nitori eyiyi tọ́ fun nyin, ẹniti o ti
bẹ̀rẹ ṣaju, kì iṣe lati ṣe nikan, ṣugbọn lati
fẹ pẹlu niwọn ọdún kan ti o kọja.
11 Njẹ nisisiyi ẹ mu ṣiṣe rẹ̀ na yi ṣẹ;
gẹgẹ bi imura ọkàn ti wà si ifẹ, bẹ̃ni ki
ṣiṣe wà pẹlu lati inu ini nyin jade.
12 Nitori bi ifẹ inu ba wà ṣaju, o jasi
itẹwọgbà gidigidi nipasẹ ohun ti enia ba ni,
kì iṣe nipasẹ ohun ti on kò ni.
13 Nitori emi kò fẹ ki awọn ẹlomiran
wà ni irọrun, ki a si di ẹrù rù nyin:
14 Ṣugbọn nipa idọgba, pe li akokò
isisiyi ki ọ̀pọlọpọ ini nyin ki o le ṣe ẹkún
fun aini wọn, ki ọ̀pọlọpọ ini wọn ki o le ṣe
ẹkún fun aini nyin pẹlu: ki idọgba ki o le
wà:
15 Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Ẹniti o kó pọ̀ju,
kò ni nkan le; ẹniti o si kó kereju, kò ṣe
alainito.
16 Ṣugbọn ọpẹ́ ni fun Ọlọrun, ẹniti o fi
itara aniyan kanna yi si aiya Titu fun
nyin.
17 Nitori on gbà ọ̀rọ iyanju ti a fifun u

Digitized by Google

nitõtọ; ṣugbọn on ti mura tẹlẹ nipa ifẹ
iru rẹ̀, o si ti tọ̀ nyin wá.
18 Awa ti rán arakọnrin na pẹlu rẹ̀, iyìn
ẹniti o wà ninu ihin-rere ninu gbogbo ijọ
yiká:
19 Kì si iṣe kìki eyini nikan, ṣugbọn
ẹniti a ti yàn pẹlu lati ọdọ ijọ wá lati ma
rìn kiri pẹlu wa nipa orẹ-ọfẹ yi, ti awa nṣe
iranṣẹ rẹ̀ fun ogo Oluwa kanna, ati imura
tẹlẹ inu nyin:
20 Awa nyẹra kuro ninu eyi, ki ẹnikẹni
ki o máṣe gàn wa nitori ọ̀pọlọpọ yi ti a ṣe
itọju rẹ̀ nipasẹ wa:
21 Awa npèse fun ohun rere, kì iṣe kìki
niwaju Oluwa nikan, ṣugbọn niwaju enia
pẹlu.
22 Awa si ti rán arakọnrin wa pẹlu wọn,
ẹniti awa si ti mọ̀ daju ni ṣiṣe aisimi ni-
gbakugba ninu iṣẹ ọ̀pọlọpọ, ṣugbọn nisisiyi
melomelo julọ li aisimi rẹ̀, nipa igbẹkẹle
nla ti o ni si nyin.
23 Bi ẹnikẹni ba mbère ẹniti Titu iṣe,
olubaṣiṣẹ ati oluranlọwọ mi ni iṣe nitori
nyin: tabi awọn arakọnrin wa li ẹnikẹni
mbère ni, iranṣẹ ijọ ni nwọn iṣe, ati ogo
Kristi.
24 Nitorina ẹ fi àmi ifẹ nyin hàn wọn
niwaju ijọ, ati ṣiṣogo wa nitori nyin.

## ORI 9.

ṢUGBỌN nipa ti ipinfunni fun awọn
enia mimọ́, eyini kò yẹ fun mi lati
kọwe si nyin:
2 Nitoriti mo mọ̀ imura ọkàn nyin, ileri
ti mo ṣe fun awọn ara Makedonia pe, Akaia
ti mura tan niwọn ọdún kan ti o kọja;
itara nyin si ti mu ọ̀pọlọpọ jowú.
3 Ṣugbọn mo ti rán awọn arakọnrin, ki
ileri wa nitori nyin ki o máṣe jasi asan ni-
tori eyi; pe gẹgẹ bi mo ti wi, ki ẹnyin ki
o le mura tẹlẹ:
4 Bi awọn ará Makedonia ba bá mi wá,
ti nwọn si bá nyin li aimura tan, ki oju ki
o máṣe tì wa (laiwipe ẹnyin,) niti igbẹkẹle
ileri yi.
5 Nitorina ni mo rò pe o yẹ lati gbà
awọn arakọnrin niyanju, ki nwọn ki o
ṣaju tọ̀ nyin wá, ki ẹnyin ki o si mura
ẹ̀bun nyin tẹlẹ, gẹgẹ bi awa ti wi fun nyin
ṣaju, ki a le ṣe eyi na silẹ, ki o le jasi bi
ohun ẹ̀bun, ki o má si ṣe dabi ti ojukò-
koro.
6 Ṣugbọn eyi ni mo wi pe, Ẹniti o ba
fọnrugbin kiun, kiun ni yio ká; ẹniti o ba
si fọnrugbin pipọ, pipọ ni yio ká.
7 Ki olukuluku enia ki o ṣe gẹgẹ bi o ti
pinnu li ọkàn rẹ̀; kì iṣe afiyanjuṣe, tabi ti
alaigbọdọ má ṣe: nitori Ọlọrun fẹ oninu-
didun ọlọrẹ.
8 Ọlọrun si le mu ki gbogbo ore-ọfẹ ma
bisi i fun nyin; ẹniti o ni anito ohun gbo-
gbo ni igbagbogbo, ki ẹnyin ki o le ma pọ̀
si i ni iṣẹ rere gbogbo:
9 (Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, O ti fọn kalẹ; o
ti fifun awọn talakà: ododo rẹ̀ duro lailai.
10 Njẹ ẹniti nfi irugbin fun afunrugbin,
ati akara fun onjẹ, ki o fi irugbin fun
nyin, ki o sọ ọ di pipọ, ki o si mu eso odo-
do nyin bi si i.)
11 Ẹniti a ti ṣe li ọrọ̀ ohun gbogbo li
ọ̀pọlọpọ iṣeun, ti o si jasi ọpẹ́ fun Ọlọrun
nipa wa.
12 Nitori ti iṣẹ iranṣẹ ìsin yi ko fi kún
aini ijọ enia mimọ́ nikan, ṣugbọn o si di
pipọ pẹlu nipa ọ̀pọlọpọ ọpẹ́ fun Ọlọrun;
13 Nigbati nwọn nyin Ọlọrun logo ni-
tori ijẹwọ itẹriba nyin si ihin-rere Kristi,
nipa àmi iṣẹ ọrẹ yi, ati ọ̀pọlọpọ ipinfunni
nyin fun wọn, ati fun gbogbo enia;
14 Ati nipa adura wọn fun nyin, awọn
ẹniti o fẹ nyin nitori ọ̀pọlọpọ ore-ọfẹ Ọlọ-
run ti o wà ninu nyin.
15 Ọpẹ́ ni fun Ọlọrun nitori alailesọ
ẹ̀bun rẹ̀.

## ORI 10.

ṢUGBỌN emi Paulu tikarami fi inututù
ati ìwa pẹlẹ Kristi bẹ̀ nyin, ẹniti iṣe
alailọlá nigbati emi wà larin nyin, ṣugbọn
nigbati emi kò si, ẹniti o ni igboiya si
nyin:
2 Ṣugbọn mo bẹ̀ nyin ki emi ki o máṣe
fi igbẹkẹle nì ṣe igboiya nigbati emi wà
larin nyin, nipa eyi ti mo rò pe, mo ni
igboiya si ẹlomiran, awọn ẹniti nrò wa si
bi ẹnipe awa nrìn gẹgẹ bi ti ara.
3 Nitoripe bi awa tilẹ nrìn ni ti ara,
ṣugbọn awa kò jagun nipa ti ara:
4 (Nitori ihamọra ijagun wa kì iṣe ti
ara, ṣugbọn o li agbara nipa Ọlọrun lati
wó ibi giga palẹ;)
5 Awa nsọ gbogbo ironu buburu kalẹ,
ati gbogbo ohun giga ti ngbé ara rẹ̀ ga si
ìmọ Ọlọrun, awa si ndi gbogbo ironu ni
igbekun wá si igbagbọ́ Kristi;
6 Awa si ti mura tan lati gbẹsan gbogbo
aigbọran, nigbati igbagbọ́ nyin ba pé.
7 Ẹnyin si nwò nkan gẹgẹ bi nwọn ti fi
ara hàn lode? Bi ẹnikẹni ba gbẹkẹle ara
rẹ̀ pe, ti Kristi li on iṣe, ẹ jẹ ki on ki o si
tún rò eyi ninu ara rẹ̀ pe, bi on ti jẹ́ ti
Kristi, gẹgẹ bẹli awa si jẹ́ ti Kristi pẹlu.

Digitized by Google

8 Nitoripe bi mo tilẹ nṣeféfe diẹ nitori
agbara wa, ti Oluwa ti fifun wa fun ẹkọ́
nyin, kì iṣe fun iparun nyin, oju kì yio tì
mi:
9 Ki o máṣe dabi ẹnipe emi nfi iwe
dẹruba nyin.
10 Nitori nwọn wipe, iwe rẹ̀ wuwo,
nwọn si lagbara; ṣugbọn ìrisi rẹ̀ jẹ alai-
lera, ohùn rẹ̀ si jẹ gigan.
11 Ki irú enia bẹ̃ ki o si ronu pe, irú
ẹniti awa iṣe li ọ̀rọ nipa iwe nigbati awa kò
si, irú bẹ̃li awa o si jẹ ni ṣiṣe pẹlu nigbati
awa ba wà.
12 Nitoripe awa kò gbọdọ kà ara wa mọ́
iye wọn, tabi ki a da ara wa pọ̀ mọ́ awọn
miran ti nyìn ara wọn: ṣugbọn nwọn nfi
ara wọn diwọ̀n ara wọn, nwọn si fi ara wọn
we ara wọn ninu wọn, nwọn kò moye.
13 Ṣugbọn awa kò ṣeféfe nkan wọnni ti
o kọja ipá wa, ṣugbọn gẹgẹ bi ìwọn àla ti
Ọlọrun ti pín fun wa, ani àla kan lati de
ọdọ nyin.
14 Nitori awa kò nawọ́ wa rekọja àla wa,
bi ẹnipe awa kò de ọdọ nyin: nitori awa
ti de ọdọ nyin pẹlu lati ma wasu ihin-rere
Kristi:
15 Awa kò ṣeféfe nkan wọnni ti o rekọja
àla wa, eyini ni nipa iṣẹ ẹlomiran; ṣugbọn
awa ni ireti pe, nigbati igbagbọ́ nyin ba di
pipọ, awa o di gbigbega lọdọ nyin gẹgẹ bi
àla wa lọpọlọpọ.
16 Lati wasu ihin-rere ni ẹkùn ti mbẹ
niwaju nyin, li aiṣeféfe ninu àla ẹlomiran
nipa ohun ti a ti ṣe tẹlẹ si wa lọwọ.
17 Ṣugbọn ẹniti o ba nṣeféfe, ki o mã
ṣeféfe ninu Oluwa.
18 Nitoripe kì iṣe ẹniti nyìn ara rẹ̀ li
amọ̀daju, bikoṣe ẹniti Oluwa yìn.

## ORI 11.

ENYIN iba jẹ gbà mi diẹ ninu wère mi,
ati nitotọ, ẹ gbà mi.
2 Nitoripe emi njowú lori nyin niti owú
ẹni ìwa-bi-Ọlọrun: nitoriti mo ti fi nyin
fun ọkọ kan, ki emi ki o le mu nyin wá bi
wundia ti kò lẹgan sọdọ Kristi.
3 Ṣugbọn omnú nkọ mi pe, gẹgẹ bi ejò
ti tàn Efa jẹ nipasẹ arekereke rẹ̀, ki a máṣe
mu ọkàn nyin bajẹ kuro ninu otitọ ti o wà
ninu Kristi bẹ̃ gẹgẹ nipasẹ ohunkohun.
4 Nitoripe bi ẹniti mbọ̀ wá ba nwasu
Jesu miran, ẹniti awa kò ti wasu ri, tabi
bi ẹnyin ba gbà ẹmí miran, ti ẹnyin kò ti
gbà, tabi ihin-rere miran, ti ẹnyin kò ti
tẹwọgbà, ẹnyin iba le fi ayọ̀ gbà a.
5 Nitori mo rò pe emi kò rẹ̀hin li ohun-
kohun si awọn Aposteli giga na.
6 Ṣugbọn bi mo tilẹ jẹ òpe li ọ̀rọ, ki iṣe
ni ìmọ; ṣugbọn awa ti di ẹniti a ti fihàn
daju larin nyin li ohun gbogbo.
7 Ẹṣẹ ni mo ha ti ndá, niti emi nrẹ̀ ara
mi silẹ ki a le gbé nyin leke, nitoriti mo ti
wasu ihin-rere Ọlọrun fun nyin lọfẹ?
8 Emi nkó ini ijọ miran, emi ngbà owo
lọwọ wọn lati fi sìn nyin.
9 Nigbati mo si wà pẹlu nyin, ti mo si
ṣe alaini, emi kò ná ẹnikẹni li owo: ni-
toriti ohun ti o kù fun mi awọn ará ti o ti
Makedonia wá fi kún u: emi si ti pa ara
mi mọ́ kuro ninu ohun gbogbo, ki emi ki o
máṣe jasi oniyọnu fun nyin, bẹ̃li emi o si
ma pa ara mi mọ́.
10 Bi otitọ Kristi ti mbẹ ninu mi, kò si
ẹniti o le da mi lẹkun iṣeféfe yi ni gbogbo
ẹkùn Akaia.
11 Nitori kini? nitori emi kò fẹ nyin ni
bi? Ọlọrun mọ̀.
12 Ṣugbọn ohun ti mo ti nṣe li emi o si
ma ṣe, ki emi ki o le ke ẹfẹ́ kuro lọwọ
awọn ti nfẹ́ ẹfẹ́; pe nipa ohun ti nwọn
nṣeféfe si, ki a le ri wọn gẹgẹ bi awa.
13 Nitori irú wọn li awọn eke Aposteli,
awọn ẹniti nṣiṣẹ ẹ̀tan, ti npa ara wọn dà
di Aposteli Kristi.
14 Kì si iṣe ohun iyanu; nitori Satani
tikararẹ̀ ama pa ara rẹ̀ dà di angeli imọlẹ.
15 Nitorina kì iṣe ohun nla bi awọn
iranṣẹ rẹ̀ pẹlu ba pa ara wọn dà bi awọn
iranṣẹ ododo; igbẹhin awọn ẹniti yio ri
gẹgẹ bi iṣẹ wọn.
16 Mo si tún wipe, Ki ẹnikẹni ki o máṣe
rò pe aṣiwère ni mi; bi ko si jẹ bẹ̃, ṣugbọn
bi aṣiwère ẹ gbà mi, ki emi ki o le gbé ara
mi ga diẹ.
17 Ohun ti emi nsọ, emi kò sọ ọ nipa ti
Oluwa, ṣugbọn bi ẹnipe alaimoye, ninu iṣe-
féfe dajudaju yi.
18 Ọpọlọpọ li o sa nṣogo nipa ti ara, emi
o ṣogo pẹlu.
19 Nitori ẹnyin fi inu-didùn gbà awọn
aṣiwère, nigbati ẹnyin tikara nyin jẹ
ọlọ́gbọn.
20 Nitori ẹnyin gbà pe, bi ẹnikan ba
sọ nyin di ondè, bi ẹnikan ba gbé nyin mì,
bi ẹnikan ba gbà lọwọ nyin, bi ẹnikan ba
gbé ara rẹ̀ ga, bi ẹnikan ba gbá nyin loju,
21 Emi nwi lọna ẹ̀gan, bi ẹnipe awa ti
jẹ alailera. Ṣugbọn ninu ohunkohun ti
ẹnikan ni igboiya, (emi nsọ werewère,) emi
ni igboiya pẹlu.
22 Heberu ni nwọn bi? bẹ̃li emi. Ara

F F

Digitized by Google

Israeli ni nwọn bi? bẹ̀li emi. Irú ọmọ
Abrahamu ni nwọn bi? bẹ̀li emi.
23 Iranṣẹ Kristi ni nwọn bi? (emi nsọ
bi aṣiwère) mo ta wọn yọ; niti iṣẹ lọpọ-
lọpọ, niti paṣan mo rekọja, niti tubu
nigbakugba, niti ikú nigbagbogbo.
24 Nigba marun ni mo gbà paṣan mọ-
kandilogoji lọwọ awọn Ju.
25 Nigba mẹta li a fi ọgọ lù mi, nigba
kan li a sọ mi li okuta, nigba mẹta li ọkọ̀
rì mi, lọsán ati loru ni mo ti wà ninu ibú;
26 Ni ìrin àjo nigbakugba, ninu ewu
omi, ninu ewu awọn ọlọṣa, ninu ewu awọn
ara ilu mi, ninu ewu awọn keferi, ninu
ewu ni ilu, ninu ewu li aginjù, ninu ewu
loju okun, ninu ewu larin awọn eke ara-
kọnrin:
27 Ninu ãrẹ̀ ati irora, ninu iṣọra nigba-
kugba, ninu ebi ati orùngbẹ, ninu àwẹ
nigbakugba, ninu otutù ati ìhoho.
28 Pẹlu nkan wọnni ti o wà lode, eyi ti
nwọjọ ti mi li ojojumọ́, aniyan gbogbo ijọ.
29 Tani iṣe alailera, ti emi kò ṣe alai-
lera? tabi tali a mu kọsẹ̀, ti ara mi kò
gbina?
30 Bi emi kò le ṣaima ṣogo, emi o kuku
mã ṣogo nipa awọn nkan ti iṣe ti ailera mi.
31 Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa
wa, ẹniti iṣe olubukún julọ lailai, mọ̀ pe
emi kò ṣeke.
32 Ni Damasku, bãlẹ ti o wà labẹ ọba
Areta fi ẹgbẹ ogun ká ilu awọn ara Damas-
ku mọ́, o nfẹ mi lati mu:
33 Ati loju ferese ninu agbọ̀n li a si ti
sọ̀ mi kalẹ lẹhin odi, ti mo si bọ́ lọwọ rẹ̀.

ORI 12.

LI aiṣiyemeji, kò ṣe anfani fun mi lati
ma ṣeféfe. Nitori emi o wá si iran
ati iṣipaya ti Oluwa.
2 Emi ti mọ̀ ọkọnrin kan ninu Kristi
nwọn ọdún mẹrinla ti o kọja, (yala ninu
ara ni, emi kò mọ̀; tabi lati ara kuro ni,
emi kò mọ̀: Ọlọrun li o mọ̀;) a gbé irú
enia bẹ̃ lọ si ọrun kẹta.
3 Emi si ti mọ̀ irú ọkọnrin bẹ̃, (yala li
ara ni, tabi lati ara kuro ni, emi kò mọ̀:
Ọlọrun li o mọ̀;)
4 Bi a ti gbé e lọ soke paradise, ti o si
ti gbọ́ ọ̀rọ ti a kò le sọ, eyiti kò tọ́ fun
enia lati ma sọ jade.
5 Nipa irú ẹni bẹ̃ li emi o ma ṣeféfe:
ṣugbọn nipa ti emi tikarami emi kì yio
ṣeféfe, bikoṣe ninu ailera mi.
6 Nitoripe bi emi tilẹ nfẹ mã ṣogo, emi
kì yio jẹ aṣiwère; nitoripe emi o sọ otitọ:
ṣugbọn nisisiyi mo kọ̀, ki ẹnikẹni ki o
máṣe fi mi pè jù ẹniti o ri ti emi iṣe lọ,
tabi jù eyiti o gburó mi si.
7 Ati nitori ki emi ki o má ba gbé ara
mi ga rekọja nipasẹ ọ̀pọlọpọ iṣipaya, a si ti
fi ẹgún gún mi lara, iranṣẹ Satani lati kọlù
mi, nitori ki emi ki o má ba gbé ara mi ga
rekọja.
8 Nitori nkan yi ni mo ṣe bẹ̀ Oluwa
nigba mẹta pe, ki o le kuro lara mi.
9 On si wi fun mi pe, Ore-ọfẹ mi to fun
ọ: nitoripe a sọ agbara mi di pipé ninu
ailera. Nitorina tayọ̀tayọ̀ li emi o kuku
ma ṣogo ninu ailera mi, ki agbara Kristi
ki o le ma wà lara mi.
10 Nitorina emi nṣe inu-didùn ninu
ailera gbogbo, ninu ẹ̀gan gbogbo, ninu aini
gbogbo, ninu inunibini gbogbo, ninu
wahalà gbogbo nitori Kristi: nitori nigbati
mo ba di alailera, nigbana ni mo di alagbara.
11 Mo di aṣiwère nipa ṣiṣogo; ẹnyin li
o mu mi ṣe e: nitoriti o tọ́ ti a ba yìn mi
lọdọ nyin: nitoriti emi kò rẹ̀hin li ohun-
kohun si awọn Aposteli giga na, bi mo tilẹ
jasi asan.
12 Nitõtọ a ti ṣe iṣẹ àmi Aposteli larin
nyin nipa sũru gbogbo, nipa iṣẹ àmi, ati
iṣẹ iyanu, ati iṣẹ agbara.
13 Nitori ninu kili ohun ti ẹnyin rẹ̀hin
si ijọ miran, bikoṣe niti pe emi tikarami ko
jẹ ayọnilẹnu fun nyin? ẹ dari ẹ̀ṣẹ yi jì mi.
14 Kiyesi i, igba kẹta yi ni mo mura tan
lati tọ̀ nyin wá; emi kì yio si jẹ ayọnilẹnu
fun nyin: nitoriti emi kò wá nkan nyin,
bikoṣe ẹnyin tikara nyin: nitoriti kò tọ́
fun awọn ọmọ lati ma tò iṣura jọ fun awọn
õbi wọn, bikoṣe awọn õbi fun awọn ọmọ
wọn.
15 Emi o si fi ayọ̀ náwo, emi o si ná ara
mi fun ọkàn nyin nitõtọ; bi o ti jẹ pe ni-
wọn bi mo ti fẹ nyin to lọpọlọpọ, diẹ li a
fẹ mi.
16 Ṣugbọn o dara bẹ̃, ti emi kò yọ nyin
lẹnu: ṣugbọn bi ọlọ́gbọn, emi nfi ẹrọ mu
nyin.
17 Emi ha fi nyin ṣe èrè jijẹ nipa ẹnikẹni
ninu awọn ti mo rán si nyin bi?
18 Mo bẹ̀ Titu, mo si rán arakọnrin kan
pẹlu rẹ̀; Titu ha fi nyin ṣe èrè jijẹ bi? nipa
ẹmí kanna kọ́ awa nrìn bi? nipasẹ ọ̀na
kanna kọ́ awa nrìn bi?
19 Mo wi ẹ̀wẹ, ẹnyin rò pe awa nṣe awa-
wi fun ara wa nitori nyin bi? awa nsọ̀rọ
niwaju Ọlọrun ninu Kristi: ṣugbọn awa
nṣe ohun gbogbo, olufẹ ọwọn, lati mu nyin
duro.

Digitized by Google

20 Nitori omnu nkọ mi pe, nigbati mo
ba de, emi kì yio bá nyin gẹgẹ bi irú eyi ti
mo fẹ, ati pe ẹnyin o si ri mi gẹgẹ bi irú
eyi ti ẹnyin kò fẹ: ki agun, ilara, ibinu,
ìja, isọrọ ẹni lẹhin, isọrọ jẹjẹ, ihalẹ, irọkẹkẹ
ki o má ba wà:
21 Ati nigbati mo ba si pada de, ki Ọlọrun mi ki o máṣe rẹ̀ mi silẹ larin nyin, ati
pe emi o si mã sọkun nitori ọ̀pọlọpọ awọn
ti o ti ṣẹ̀ na, ti nwọn kò si ronupiwada ẹ̀ṣẹ
ìwa-ẽri, ati ti àgbere, ati ti wọ̀bia ti nwọn
ti dá.

## ORI 13.

EYI li o di igba kẹta ti emi ntọ̀ nyin wá.
Li ẹnu ẹlẹri meji tabi mẹta li a o fi
idi ọ̀rọ gbogbo mulẹ.
2 Mo ti sọ fun nyin ṣaju, mo si sọ fun
nyin tẹlẹ, bi ẹnipe mo wà pẹlu nyin nigba
keji; ati bi emi kò ti si lọdọ nyin nisisiyi,
mo kọwe si awọn ti o ti ṣẹ̀ na titi di isisiyi,
ati si gbogbo awọn ẹlomiran, pe bi mo ba
tún pada wá, emi kì yio da wọn si:
3 Nigbati ẹnyin ti nwá àmi pe Kristi
nsọ̀rọ nipa mi, ti kì iṣe ailera si nyin, ṣugbọn agbara ninu nyin.
4 Nitoripe bi a tilẹ kàn a mọ agbelebu
nipa ailera, ṣugbọn on wà lãye nipa agbara
Ọlọrun. Nitori awa pẹlu si jasi alailera
ninu rẹ̀, ṣugbọn awa o si wà lãye pẹlu rẹ̀
nipa agbara Ọlọrun si nyin.
5 Ẹ wadi ara nyin, bi ẹnyin ba wà ni
igbagbọ́; ẹ da ẹnyin tikara nyin loju.
Ẹnyin tikara nyin kò mọ̀ ara nyin daju, bi
Jesu Kristi wà ninu nyin, bikoṣepe ẹnyin
ba jẹ awọn ti aṣatì?
6 Ṣugbọn mo gbẹkẹle pe ẹnyin o mọ̀ pe,
awa kì iṣe awọn ti aṣatì.
7 Nisisiyi emi ngbadura si Ọlọrun, ki
ẹnyin ki o máṣe ibikibi kan; kì iṣe nitori
ki awa ki o le fi ara hàn bi awọn ti amọ̀daju, ṣugbọn ki ẹnyin ki o le ma ṣe eyi ti o
dara, bi awa tilẹ dabi awọn ti aṣatì.
8 Nitoriti awa kò gbọdọ ṣe ohun òdi kan
si otitọ, bikoṣe fun otitọ.
9 Nitoriti awa nyọ̀, nigbati awa jẹ alailera, ti ẹnyin si jẹ alagbara: eyi bayi li
awa si nfẹ pẹlu ani pipé nyin.
10 Nitorina nigbati emi kò si, mo kọwe
nkan wọnyi pe, nigbati mo ba wà, ki emi
ki o ma ba lò ikannú, gẹgẹ bi agbara ti
Oluwa ti fifun mi si ẹkọ́, kì si iṣe si iparun.
11 Li akotan, ará, alafia fun nyin. Ẹ jẹ
pipé, ẹ tújuka, ẹ jẹ oninu kan, ẹ mã wà li
alafia; Ọlọrun ifẹ ati ti alafia yio wà pẹlu
nyin.
12 Ẹ fi ifẹnukonu mimọ́ kí ara nyin.
13 Gbogbo ijọ enia mimọ́ kí nyin.
14 Ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa, ati ifẹ
Ọlọrun, ati ìdapọ ti Ẹmí Mimọ́, ki o wà
pẹlu gbogbo nyin. Amin.

A kọ Episteli keji si awọn ara Korinti
lati Filippi lọ, ilu kan ni Makedonia,
lati ọwọ́ Titu ati Luku.

---

EPISTELI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA GALATIA.

## ORI 1.

PAULU, Aposteli, (kì iṣe lati ọdọ enia
wá, tabi nipa enia, ṣugbọn nipa Jesu
Kristi, ati Ọlọrun Baba, ẹniti o jí i dide
kuro ninu okú;)
2 Ati gbogbo awọn arakọnrin ti o wà
pẹlu mi, si gbogbo ijọ Galatia:
3 Ore-ọfẹ sí nyin ati alafia lati ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati Jesu Kristi Oluwa wa,
4 Ẹniti o fi ara rẹ̀ fun ẹ̀ṣẹ wa, ki o le gbà
wa kuro ninu aiye buburu isisiyi, gẹgẹ bi
ifẹ Ọlọrun ati Baba wa:
5 Ẹniti ogo wà fun lai ati lailai. Amin.
6 Ẹnu yà mi nitoriti a yara kánkan mu
nyin kuro lọdọ ẹniti o pè nyin sinu ore-ọfẹ
Kristi si ihin-rere miran:
7 Eyiti kì iṣe omiran; ṣugbọn awọn kan
wà ti nyọ nyin lẹnu, nwọn si nfẹ yi ihinrere Kristi pada.
8 Ṣugbọn bi o ṣe awa ni, tabi Angeli kan
lati ọrun wá, ba wasu ihin-rere miran fun
nyin pẹlu eyi ti awa ti wasu fun nyin lọ,
jẹ ki o di ẹni ifibu.
9 Gẹgẹ bi awa ti wi ṣaju, bẹ̃ni mo si tún
wi nisisiyi pe, Bi ẹnikan ba wasu ihin-rere

Digitized by Google

miran fun nyin jù eyiti ẹnyin ti gbà lọ, jẹ
ki oluwarẹ̀ di ẹni ifibu.
10 Njẹ nisisiyi enia ni emi nyi lọkàn
pada tabi Ọlọrun ? tabi enia ni emi nfẹ lati
wù ? nitoripe bi emi ba si nwù enia, emi kì
yio le ṣe iranṣẹ Kristi.
11 Ṣugbọn mo wi fun nyin, ará, pe ihin-
rere ti mo ti wasu kì iṣe nipa ti enia.
12 Nitoripe kì iṣe lọwọ enia ni mo ti gbà
a, bẹ̃li a kò fi kọ́ mi, bikoṣe nipa ifihan
Jesu Kristi.
13 Nitori ẹnyin ti gburó ìwa mi nigba atijọ
ninu ìsin awọn Ju, bi mo ti ṣe inunibini si
ijọ enia Ọlọrun rekọja àla, ti mo si bà a jẹ:
14 Mo si ni iyìn ninu ìsin awọn Ju jù
ọ̀pọlọpọ awọn ojugbà mi lọ ninu orilẹ-ède
emi tikarami, mo si ni itara lọpọlọpọ si
ofin atọwọdọwọ awọn baba mi.
15 Ṣugbọn nigbati o wù Ọlọrun, ẹniti o
yà mi kuro lati inu iya mi wá, ti o si pè mi
nipa ore-ọfẹ rẹ̀,
16 Lati fi Ọmọ rẹ̀ hàn ninu mi, ki emi
ki o le ma wasu rẹ̀ larin awọn Keferi; loju-
kanna emi kò bá ara ati ẹ̀jẹ gbìmọ:
17 Bẹ̃ni emi kò gòke lọ si Jerusalemu tọ̀
awọn ti iṣe Aposteli ṣaju mi; ṣugbọn mo lọ
si Arabia, mo si tún pada wá si Damasku.
18 Lẹhin ọdún mẹta, nigbana ni mo
gòke lọ si Jerusalemu lati wò Peteru, mo
si gbé ọdọ rẹ̀ ni ijọ mẹdogun.
19 Ṣugbọn emi kò ri ẹnikẹni ninu awọn
Aposteli miran, bikoṣe Jakọbu arakọnrin
Oluwa.
20 Nkan ti emi nkọwe si nyin nisisiyi,
kiyesi i, emi kò ṣeke niwaju Ọlọrun.
21 Lẹhin na mo si wá si ẹkùn Siria ati
ti Kiliki;
22 Mo si jẹ ẹniti a kò mọ̀ li oju fun ijọ ti
o wà ninu Kristi ni Judea:
23 Ṣugbọn kìki nwọn ti gbọ́ pe, Ẹniti o
ti nṣe inunibini si wa ri, si nwasu igbagbọ́
na nisisiyi, ti on ti nparun lẹ̃kan.
24 Nwọn si yìn Ọlọrun logo nitori mi.

## ORI 2.

LẸHIN ọdún mẹrinla, nigbana ni mo tún
gòke lọ si Jerusalemu pẹlu Barnaba,
mo si mu Titu lọ pẹlu mi.
2 Mo si gòke lọ nipa iṣipaya, mo si sọdi
ihin-rere ni fun wọn, ti emi nwasu ninu
awọn Keferi, ṣugbọn nikọ̀kọ fun awọn ti o
ni iyìn, ki emi ki o má ba sáre, tabi ki o
má ba jẹ pe mo ti sáre lasan.
3 Ṣugbọn iba ṣe Titu, ti o wà pẹlu mi,
ẹniti iṣe ara Hellene, a kò fi agbara mu u
ati kọla:
4 Ati nitori awọn eke arakọnrin ti a
mu wọ̀ inu wa wá, ẹniti o ti ṣe amí wa
nikọ̀kọ lati ri omnira wa, ti awa ni ninu
Kristi Jesu, ki nwọn ki o le mu wa wá sinu
ìde:
5 Awọn ẹniti awa kò si fi àye fun bá,
ọdàri, kì iṣe niwọn wakati kan; ki otitọ
ìhin-rere ki o le ma wà pẹlu nyin.
6 Ṣugbọn niti awọn ti o dabi ẹni nla,
ohunkohun ti nwọn jasi, kò di nkankan
fun mi: Ọlọrun kò gbà ojurere ẹnikẹni:
nitori awọn ti o dabi alaṣẹ ni ìgbimọ, kò di
nkan fun mi:
7 Ṣugbọn ni ilodi, nigbati nwọn ri pe a
fi ihin-rere ti awọn alaikọla le mi lọwọ, bi
a ti fi ihin-rere ti awọn onila le Peteru
lọwọ;
8 (Nitoripe ẹniti o ti ṣiṣẹ aitase pipọ
nipasẹ Peteru si iṣẹ Aposteli fun awọn
ikọla, on kanna li o ṣiṣẹ ninu mi si awọn
Keferi pẹlu:)
9 Ati nigbati Jakọbu, ati Kefa, ati
Johannu, awọn ẹniti o dabi ọwọ̀n, woye
ore-ọfẹ ti a fifun mi, nwọn si fi ọwọ́ ọtún
ìdapọ fun emi ati Barnaba, pe ki awa ki o
mã lọ sọdọ awọn Keferi, ati awọn sọdọ
awọn onila.
10 Kìki ki a sá mã ranti awọn talakà ni
nwọn fẹ, ohun ti emi kò si jafara lati mã
ṣe pẹlu.
11 Ṣugbọn nigbati Peteru de Antioku,
mo dè e lọna li oju ara rẹ̀, nitori ti o jasi
ẹniti a ba bawi.
12 Nitoripe ki awọn ẹnikan ti o ti ọdọ
Jakọbu wá to de, o ti mba awọn Keferi
jẹun: ṣugbọn nigbati nwọn de, o fà sẹhin,
o si yà ara rẹ̀ si apakan, o mbẹ̀ru awọn ti
iṣe onila.
13 Awọn Ju miran si jùmọ ṣe agabagebe
bẹ̃ gẹgẹ pẹlu rẹ̀; tobẹ̃ ti nwọn si fi agaba-
gebe wọn fà Barnaba lọ pẹlu.
14 Ṣugbọn nigbati mo ri pe nwọn kò rìn
dẽdẽ gẹgẹ bi otitọ ihin-rere, mo wi fun
Peteru niwaju gbogbo wọn pe, Bi iwọ, ti
iṣe Ju, ba nrìn gẹgẹ bi ìwa awọn Keferi,
laiṣe bi awọn Ju, ẽṣe ti iwọ fi nfi agbara
mu awọn Keferi lati ma rìn bi awọn
Ju.
15 Awa ti iṣe Ju nipa ẹda, ti kì iṣe ẹlẹṣẹ
ti awọn Keferi,
16 Awa mọ̀ pe a ko da ẹnikẹni lare nipa
iṣẹ ofin, bikoṣe nipa igbagbọ́ Jesu Kristi,
ani awa na gbà Jesu Kristi gbọ́, ki a ba le
da wa lare nipa igbagbọ́ ti Kristi, kì iṣe
nipa iṣẹ ofin: nitoripe nipa iṣẹ ofin kò si
ẹda ti a o dalare.

Digitized by Google

17 Ṣugbọn bi, nigbati awa ba nwá ọ̀na
lati ri idalare nipa Kristi, ti a si nri ti awa
tikarawa jasi ẹlẹṣẹ pẹlu, njẹ́ Kristi ha ṣe
iranṣẹ ẹ̀ṣẹ bi? ki a má ri i.
18 Nitoripe bi mo ba si tun gbé ohun ti
mo ti wó palẹ ró, mo sọ emi tikarami di
ẹlẹṣẹ.
19 Nitoripe nipa ofin, mo ti kú si ofin,
ki emi ki o le wà lãye si Ọlọrun.
20 A ti kàn mi mọ agbelebu pẹlu Kristi:
ṣugbọn mo wà lãye; ṣugbọn ki iṣe emi,
bikoṣe Kristi ti o wà lãye ninu mi: ati
wiwà lãye ti mo wà nipa ti ara, emi wà
lãye nipa igbagbọ́ Ọmọ Ọlọrun, ẹniti o fẹ
mi, ti o si ti fi on tikararẹ̀ fun mi.
21 Emi kò sọ ore-ọfẹ Ọlọrun dasan: ni-
toripe bi ododo ba ti ipa ofin wá, njẹ Kristi
kú lasan.

## ORI 3.

ENYIN alaironu ara Galatia, tani o ha
tàn nyin jẹ, ki ẹnyin ki o máṣe gbà
otitọ gbọ́, li oju ẹniti a gbé Jesu Kristi
kalẹ, ti a si kàn a mọ agbelebu larin nyin?
2 Kìki eyi ni mo fẹ mọ̀ lọwọ nyin pe,
Nipa iṣẹ ofin li ẹnyin gbà Ẹmí bi, tabi
nipa igbọran igbagbọ́?
3 Bayi li ẹnyin ṣe wère to? ẹnyin ti o ti
bẹ̀rẹ nipa ti Ẹmí, a ha ṣe nyin pé nisisiyi
nipa ti ara?
4 Lasan li ẹnyin ti jìya ọ̀pọlọpọ nkan
wọnni? bi o tilẹ ṣepe lasan li o jasi.
5 Nitorina ẹniti o bùn nyin li Ẹmí na,
ti o si nṣe iṣẹ iyanu larin nyin, nipa iṣẹ
ofin li o fi nṣe e bi? tabi nipa igbọran
igbagbọ́?
6 Gẹgẹ bi Abrahamu ti gbà Ọlọrun gbọ́,
a si kà a si fun u li ododo.
7 Ki ẹnyin ki o mọ̀ nisisiyi pe awọn
ti iṣe ti igbagbọ́, awọn na ni iṣe ọmọ
Abrahamu.
8 Iwe-mimọ́ si ti ri i tẹlẹ pe, Ọlọrun
yio dá awọn Keferi lare nipa igbagbọ́, a
ti wasu rẹ̀ ṣaju ihin-rere fun Abrahamu, o
nwipe, Nipasẹ rẹ li a o bukún fun gbogbo
orilẹ-ède.
9 Gẹgẹ bẹ̃li awọn ti iṣe ti igbagbọ́ li ẹni
alabukún-fun pẹlu Abrahamu olododo.
10 Nitoripe iye awọn ti mbẹ ní ipa iṣẹ
ofin mbẹ labẹ egun: nitoriti a ti kọ ọ
pe, Ifibu ni olukuluku ẹniti kò duro ninu
ohun gbogbo ti a kọ sinu iwe ofin lati ma
ṣe wọn.
11 Ṣugbọn o ti farahàn gbangba pe, a
kò da ẹnikẹni lare niwaju Ọlọrun nipa iṣẹ
ofin: nitoripe, Olododo yio yè nipa igbagbọ́.
12 Ofin kì si iṣe ti igbagbọ́: ṣugbọn
Ẹniti nṣe wọn yio yè nipasẹ wọn.
13 Kristi ti rà wa pada kuro lọwọ egun
ofin, ẹniti a fi ṣe egun fun wa: nitoriti a
ti kọ ọ pe, Ifibu li olukuluku ẹniti a fi há
sori igi:
14 Ki ibukún Abrahamu ki o le wá sori
awọn Keferi nipa Jesu Kristi; ki awa ki o
le gbà ileri Ẹmí nipa igbagbọ́.
15 Ará, emi nsọ̀rọ gẹgẹ bi ìwa enia; Bi
o tilẹ ṣepe majẹmu enia ni, ṣugbọn bi a ba
ti fi idi rẹ̀ mulẹ, kò si ẹniti o si le sọ ọ
dasan, tabi ti o si le fi kún u mọ́.
16 Njẹ nisisiyi fun Abrahamu ati fun
irú-ọmọ rẹ̀ li a ti ṣe ileri wọnni. On kò
wipe, Fun awọn irú ọmọ, bi ẹnipe ọ̀pọlọpọ;
ṣugbọn bi ẹnipe ọkan, Ati fun irú-ọmọ rẹ,
eyiti iṣe Kristi.
17 Eyi ni emi nwi pe, majẹmu nì, ti
Ọlọrun ti muṣẹ niṣaju, nipasẹ Kristi, ani
ofin ti o de lẹhin ọgbọ̀n-le-nirinwo ọdún
kò le sọ ọ dasan, ti a ba fi mu ileri na
tase.
18 Nitoripe bi ilẹnini na ba ṣe ti ofin, kì
iṣe ti ileri mọ́: ṣugbọn Ọlọrun ti fi i fun
Abrahamu nipa ileri.
19 Njẹ kili ofin ha jasi? A fi kún u
nitori ẹ̀ṣẹ, titi irú-ọmọ ti a ti ṣe ileri fun
yio fi de; a si ti ipasẹ awọn angeli ṣe ìlana
rẹ̀ lati ọwọ́ onilaja kan wá.
20 Njẹ onilaja kì iṣe onilaja ti ẹnikan,
ṣugbọn ọkan li Ọlọrun.
21 Nitorina ofin ha nṣe ìdena si ileri
Ọlọrun bi? Ki a má ri i: nitori ibaṣepe
ofin kan ti wà ti a fi funni, ti o le fi ìye
funni, nitõtọ ododo iba ti ipasẹ ofin
wá.
22 Ṣugbọn iwe-mimọ́ ti há gbogbo wọn
mọ́ sabẹ ẹ̀ṣẹ, ki a le fi ileri nipa igbagbọ́
Jesu Kristi fun awọn ti o gbagbọ́.
23 Ṣugbọn ki igbagbọ́ to de, a ti pa wa
mọ́ labẹ ofin, a si há wa mọ́ de igbagbọ́ ti a
o fihàn nikẹhin.
24 Nitorina ofin li o jasi olukọni lati mu
ni wá fun Kristi, ki a le da wa lare nipa
igbagbọ́.
25 Ṣugbọn lẹhin igbati igbagbọ́ ti de,
awa kò si labẹ olukọni mọ́.
26 Nitoripe awọn ọmọ Ọlọrun ni gbogbo
nyin, nipa igbagbọ́ ninu Kristi Jesu.
27 Nitoripe iye ẹnyin ti a ti baptisi sinu
Kristi, ti mu Kristi wọ̀.
28 Kò si ẹniti iṣe Ju tabi Hellene, kò si
ẹniti iṣe ẹrú tabi omnira, kò si ẹniti iṣe
ọkọnrin tabi obirin: nitoripe ọkan ni gbo-
gbo nyin jasi ninu Kristi Jesu.

Digitized by Google

29 Ati bi ẹnyin ba ṣe ti Kristi, njẹ ẹnyin
ni irú-ọmọ Abrahamu, ati arole gẹgẹ bi
ileri.

## ORI 4.

NJẸ mo ni, Arole na, niwọn igbati o ba
wà li ewe, kò yàtọ si ẹrú, bi on tilẹ
jasi oluwa gbogbo wọn;
2 Ṣugbọn o wà labẹ olukọ ati olutọju
titi fi di akokò ti baba ti yàn tẹlẹ.
3 Gẹgẹ bẹ̃ si li awa, nigbati awa ti wà li
ewe, awa ti wà li ondè labẹ ipilẹṣẹ ẹda:
4 Ṣugbọn nigbati akokò kíkun na de,
Ọlọrun rán Ọmọ rẹ̀ jade, ẹniti a bí ninu
obirin, ti a bí labẹ ofin,
5 Lati da awọn ti mbẹ labẹ ofin ni ìde,
ki awa ki o le gbà isọdọmọ awọn ọmọ.
6 Ati nitori ti ẹnyin iṣe ọmọ, Ọlọrun si
ti rán Ẹmí Ọmọ rẹ̀ wá si nyin li àiya, ti
nke pe, Abba, Baba.
7 Nitorina iwọ kì iṣe ẹrú mọ́, bikoṣe
ọmọ; ati bi iwọ ba iṣe ọmọ, njẹ iwọ di arole
Ọlọrun nipasẹ Kristi.
8 Ṣugbọn nigbati ẹnyin kò ti mọ̀ Ọlọrun
ri, ẹnyin ti nṣe ìsin fun awọn ti kì iṣe
Ọlọrun nipa ti ẹda.
9 Ṣugbọn nisisiyi, lẹhin igbati ẹnyin ti
mọ̀ Ọlọrun tan, tabi ki a sá kuku wipe, ẹ
di mimọ̀ fun Ọlọrun, ẽha ti ri ti ẹ fi tun
yipada si alailera ati alagbe ipilẹṣẹ ẹda,
nibiti ẹnyin si nfẹ tun pada wá idi ondè?
10 Ẹnyin nkiyesi ọjọ, ati oṣù, ati akokò,
ati ọdún.
11 Omnu nkọ mi nitori nyin, ki o má
ba ṣe pe lasan ni mo ti ṣe lãlã lori nyin.
12 Ará, mo bẹ̀ nyin, ẹ mã wà bi emi ti
wà; nitoripe emi wà bi ẹnyin ti wà; ẹn-
yin kò ṣe mi ni iwọsi kan rara.
13 Ẹnyin mọ̀ bi o ti jẹ pe nipa ailera
ara ni mo fi wasu ihin-rere fun nyin niṣaju.
14 Ati idanwò mi ti iṣe ti ara mi ẹnyin
kò kẹgan, ẹnyin kò si kọ̀; ṣugbọn ẹnyin
gbà mi bi angeli Ọlọrun, ani bi Kristi
Jesu.
15 Njẹ ibukun na ti ẹnyin ti wi ha da?
nitoriti mo gbà ẹrí nyin jẹ pe, bi o le ṣe
ẹnyin iba ti yọ oju ẹnyin tikara nyin jade,
ẹnyin iba si ti fi wọn fun mi.
16 Njẹ ọtá nyin ni mo ha dà, nitori mo
sọ otitọ fun nyin bi?
17 Nwọn fi itara wá nyin, ṣugbọn ki iṣe
lọna rere; nwọn nfẹ mu nyin kuro, ki
ẹnyin ki o le mã wá wọn.
18 Ṣugbọn o dara lati ma fi itara wá ni li
ohun rere nigbagbogbo, kì si iṣe nigbati
mo wà pẹlu nyin nikan.
19 Ẹnyin ọmọ mi kekere, nitori ẹniti
mo tún nrọbi lẹ̃keji titi a o fi dá Kristi ninu
nyin,
20 Emi ńfẹ lati wà pẹlu nyin nisisiyi,
ki emi ki o si yi ohùn mi pada; nitoripe
emi nṣiyemeji nitori nyin.
21 Ẹ wi fun mi, ẹnyin ti nfẹ wà labẹ ofin,
ẹnyin kò gbọ̀rọ ofin?
22 Nitori a ti kọwe rẹ̀ pe, Abrahamu li
ọmọ ọkọnrin meji, ekini nipa ẹrú-obirin,
ekeji nipa omnira-obirin.
23 Ṣugbọn a bí eyiti iṣe ti ẹrú-obirin
nipa ti ara; ṣugbọn eyi ti omnira-obirin li
a bí nipa ileri.
24 Nkan wọnyi ti iṣe apẹrẹ: nitoripe
awọn wọnyi ni majẹmu meji nì; ekini
lati ori òke Sinai wá, ti a bí li oko-ẹrú, ti
iṣe Hagari.
25 Nitoripe Hagari yi ni ori òke Sinai
ni Arabia, ti o si wà bakanna bi Jerusa-
lemu ti o wà nisisiyi, ti o si wà li oko-ẹrú
pẹlu awọn ọmọ rẹ̀.
26 Ṣugbọn omnira ni Jerusalemu ti o wà
loke, ti iṣe iya gbogbo wa.
27 Nitoriti a ti kọwe rẹ̀ pe, Mã yọ̀ iwọ
àgan ti kò bímọ: bú ki o si kigbe soke,
iwọ ti kò rọbi ri; nitoripe ẹni alahoro ní
ọ̀pọlọpọ ọmọ jù ẹniti iṣe abilekọ lọ.
28 Ṣugbọn awa, ará, bi Isaaki ti jasi,
awa ni iṣe awọn ọmọ ileri.
29 Ṣugbọn bi igbana eyiti a bí nipa ti
ara ti ṣe inunibini si eyiti a bí nipa ti Ẹmí,
gẹgẹ bẹ̃li o jasi nisisiyi.
30 Ṣugbọn iwe-mimọ́ ha ti wi? Lé ẹrú-
obirin na jade ati ọmọ rẹ̀: nitoripe ọmọ
ẹrú-obirin kì yio ba ọmọ omnira-obirin ṣe
ajumọjogun pọ̀.
31 Nitorina, ará, awa kì iṣe ọmọ ẹrú-
obirin, bikoṣe ti omnira.

## ORI 5.

NITORINA ẹ duro ṣinṣin ninu omnira na
nipa eyi ti Kristi fi sọ wa di omnira,
ki ẹ máṣe tún fi ọrùn bọ àjaga ẹrú mọ́.
2 Kiyesi i, emi Paulu li o wi fun nyin
pe, bi a ba kọ nyin nila, Kristi ki yio li ère
fun nyin li ohunkohun.
3 Mo si tún sọ fun olukuluku enia ti o
kọla pe, o di ajigbese lati pa gbogbo ofin
mọ́.
4 Kristi kò jasi ire kan fun ẹnikẹni
ninu nyin, ti a ba ndalare nipa iṣẹ ofin;
ẹnyin ti ṣubu kuro ninu ore-ọfẹ.
5 Nitori nipa ti Ẹmí, awa nfi ireti ṣe
afojusọ̀na ododo nipa igbagbọ́.
6 Nitori ninu Jesu Kristi ikọla kò di

Digitized by Google

ohunkohun, tabi aikọla; ṣugbọn igbagbọ́
ti nṣiṣẹ nipa ifẹ.
7 Ẹnyin ti sáre gidigidi nitõtọ; tani ha
da nyin pada ki ẹnyin ki o máṣe gbà otitọ
gbọ́?
8 Iyipada ọkàn yi kò ti ọwọ́ ẹniti o pè
nyin wá.
9 Iwukara kiun ni imu gbogbo iyẹfun wu.
10 Mo ti ni igbẹkẹle si nyin nipa Oluwa
pe, ẹnyin kì yio ṣe itọju ohunkohun
miran; ṣugbọn ẹniti nyọ nyin lẹnu yio rù
idajọ tirẹ̀, ẹnikẹni eyi o wù ki o ṣe.
11 Ati emi, ará, bi emi ba si nwasu
ikọla titi di isisiyi, ehatiṣe ti emi fi njìya
nipa inunibini? njẹ ikọsẹ̀ agbelebu pari.
12 Mo tilẹ fẹ ti a ba ke awọn ti nyọ nyin
lẹnu kuro.
13 Nitori a ti pè nyin sinu omnira, ará;
kìki pe ki ẹ máṣe lò omnira fun àye si ara,
ṣugbọn nipa ifẹ ẹ mã sìn ọmọnikeji nyin.
14 Nitoripe a kó gbogbo ofin já ninu
ọ̀rọ kan, ani ninu eyi pe; Iwọ fẹ ọmọ-
nikeji rẹ bi ara rẹ.
15 Ṣugbọn bi ẹnyin ba mbù ẹnikeji nyin
ṣán, ti ẹnyin ba si npa ara nyin run, kiye-
sara ki ẹ máṣe run ara nyin.
16 Njẹ mo ni, Ẹ ma rìn nipa ti Ẹmí, ki
ẹ má si ṣe mu ifẹkufẹ ti ara ṣẹ.
17 Nitoriti ara nṣe ifẹkufẹ lodi si Ẹmí,
ati Ẹmí lodi si ara: awọn wọnyi si ṣe olodi
si ara wọn, ekini si ekeji: bẹ̃li ẹnyin kò le
ṣe ohun ti ẹnyin nfẹ.
18 Ṣugbọn bi a ba nṣe amọ̀na nyin lati
ọdọ Ẹmí wá, ẹnyin kò si labẹ ofin.
19 Njẹ awọn iṣẹ ti ara farahàn nisisiyi,
ti iṣe wọnyi; panṣaga, àgbere, ìwa-ẽri,
wọ̀bia,
20 Ibọriṣa, oṣó, irira, ìja, ilara, ibinu,
asọ, ìṣọtẹ, adamọ̀,
21 Arankàn, ipania, imọtipara, aiye
ajẹju, ati irú wọnni: awọn ti mo ti sọ fun
nyin ṣaju, gẹgẹ bi mo si ti sọ fun nyin tẹlẹ
ri pe, awọn ti nṣe nkan bawọnni kì yio
jogún ijọba Ọlọrun.
22 Ṣugbọn awọn eso ti Ẹmí ni ifẹ, ayọ̀,
alafia, ipamọra, ìwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ́,
23 Iwa tutù, ati airekọja: ofinkofin kò
lodi si irú wọnni.
24 Awọn ti iṣe ti Kristi ti kàn ara mọ
agbelebu pẹlu ifẹ ọkàn ati ifẹkufẹ rẹ̀.
25 Bi awa ba wà lãye nipa ti Ẹmí, ẹ jẹ
ki a si mã rìn nipa ti Ẹmí.
26 Ẹ máṣe jẹ ki a ma ṣafẹri ogo asan mọ́,
lati mu ẹnikeji wa binu, lati mã ṣe ilara
ọmọnikeji wa.

## ORI 6.

ARÁ, bi a ba ri ẹnikan ninu iṣubu kan,
ki ẹnyin ti iṣe ti ẹmí ki o mu irú
enia bẹ̃ bọ̀ sipò nipa ẹmí ìwa-tutù; mã
kiyesara rẹ, ki a má ba dán ọ wò pẹlu.
2 Ẹ mã rù ẹrù ọmọnikeji nyin, bẹ̃ni ki ẹ
si mu ofin Kristi ṣẹ.
3 Nitori bi enia kan ba nrò ara rẹ̀ pe
ẹnikan nla li on, nigbati kò nilari, o ntàn
ara rẹ̀ jẹ.
4 Ṣugbọn ki olukuluku ki o mọ̀ iṣẹ ara
rẹ̀ daju, nigbana ni yio si li ayọ̀ ninu ara
rẹ̀ nikan, ki yio si ṣe ti ẹlomiran.
5 Nitori olukuluku yio rù ẹrù ara rẹ̀.
6 Ṣugbọn ẹniti a nkọ́ ninu ọ̀rọ na ki o
mã pèse fun ẹniti nkọ́ni li ohun rere gbogbo.
7 Ki a máṣe tàn nyin jẹ; a kò le kẹgan
Ọlọrun: nitori ohunkohun ti enia ba fọn-
rugbin rẹ̀, on ni yio si ká pẹlu.
8 Nitori ẹniti o ba nfọnrugbin sipa ti
ara rẹ̀, nipa ti ara ni yio ká idibajẹ; ṣu-
gbọn ẹniti o ba nfọnrugbin sipa ti Ẹmí,
nipa ti Ẹmí ni yio ká ìye ainipẹkun.
9 Ki ẹ má si jẹ ki agara da wa ni rere
iṣe: nitori awa o ká nigbati akokò ba de,
bi awa kò ba ṣe ãrẹ̀.
10 Njẹ bi awa ti ri ìgba, ẹ jẹ ki a mã
ṣore fun gbogbo enia, ati pẹlupẹlu fun
awọn ti iṣe arãle igbagbọ́.
11 Ẹ wò iwe gàdàgbà-gàdàgbà ti mo fi
ọwọ ara mi kọ si nyin.
12 Iye awọn ti nfẹ ṣe ifihàn rere li ara,
nwọn nrọ̀ nyin lati kọla; nitori ki nwọn ki
o máṣe jìya inunibini nitori agbelebu Kristi.
13 Nitori awọn ti a kọ-nilà pãpã kò pa
ofin mọ́, ṣugbọn nwọn nfẹ mu nyin kọla,
ki nwọn ki o le ma ṣogo lori ara nyin.
14 Ṣugbọn ki a máṣe ri pe emi nṣogo,
bikoṣe ninu agbelebu Jesu Kristi Oluwa
wa, nipasẹ ẹniti a ti kàn aiye mọ agbelebu
fun mi, ati emi fun aiye.
15 Nitoripe ninu Kristi Jesu ikọla kò di
ohunkohun, tabi aikọla, bikoṣe ẹda titun.
16 Iye awọn ti o si nrìn gẹgẹ bi ìwọn yi,
alafia lori wọn, ati ãnu, ati lori Israeli
Ọlọrun.
17 Lati isisiyi lọ, ki ẹnikẹni máṣe yọ mi
lẹnu mọ́: nitori emi nrù apá Jesu Oluwa
kiri li ara mi.
18 Ará, ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa,
ki o wà pẹlu ẹmí nyin. Amin.

---

Si awọn Galatia ti a kọ lati Romu wá.

Digitized by Google

EPISTELI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA EFESU.

## ORI 1.

PAULU, Aposteli Jesu Kristi nipa ifẹ
Ọlọrun, si awọn enia mimọ́ ti o wà ni
Efesu, ati si awọn olododo ninu Kristi Jesu :
2 Ore-ọfẹ si nyin, ati alafia, lati ọdọ Ọlọ-
run Baba wá, ati Jesu Kristi Oluwa.
3 Olubukún li Ọlọrun ati Baba Jesu
Kristi Oluwa wa, ẹniti o ti fi gbogbo ibu-
kún ẹmí li ohun ọrun bukún wa ninu
Kristi :
4 Gẹgẹ bi o ti yàn wa ninu rẹ̀ ṣaju ipi-
lẹṣẹ aiye, ki awa ki o le jẹ mimọ́ ati alaila-
bùku niwaju rẹ̀ nipa ifẹ :
5 Ẹniti o ti yàn wa tẹlẹ si isọdọmọ awọn
ọmọ nipa Jesu Kristi fun ara rẹ̀, gẹgẹ bi ifẹ
inu-rere rẹ̀ :
6 Fun iyìn ogo ore-ọfẹ rẹ̀, eyiti o ti sọ
wa di ẹni itẹwọgbà ninu Ayànfẹ nì.
7 Ninu ẹniti awa ti ni idande nipa ẹ̀jẹ
rẹ̀, idariji ẹ̀ṣẹ, gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ ore-ọfẹ
rẹ̀ ;
8 Eyiti o ti fi gbogbo ọgbọ́n ati oye ṣe
fun wa lọpọlọpọ ;
9 Ẹniti o ti fi ohun ijinlẹ ifẹ rẹ̀ hàn wa,
gẹgẹ bi ifẹ inu-rere rẹ̀, eyiti o ti pinnu rẹ̀
ninu on tikararẹ̀ :
10 Pe nigba kíkun akokò ti a yàn tẹlẹ
fun iṣẹ iriju ki o le kojọ ninu ẹnikan, ohun
gbogbo ninu Kristi, iba ṣe eyiti mbẹ li
ọrun, ati eyiti mbẹ li aiye ; ani ninu rẹ̀ :
11 Ninu ẹniti awa pẹlu ti ri ilẹnini kan
gbà, awa ti a ti yàn tẹlẹ gẹgẹ bi ipinnu
ẹniti nṣiṣẹ ohun gbogbo gẹgẹ bi ìmọ ifẹ on
tikararẹ̀ :
12 Ki awa ki o le jẹ iyìn ogo rẹ̀, ẹniti o
tẹte gbẹkẹle Kristi.
13 Ninu ẹniti ẹnyin pẹlu gbẹkẹle, lẹhin
igbati ẹnyin ti gbọ́ ọ̀rọ otitọ nì, ihin-rere
igbala nyin : ati pẹlu lẹhin igbati ẹnyin
gbagbọ́, ninu ẹniti a fi Ẹmí Mimọ́ ileri ṣe
èdidi nyin,
14 Ẹniti iṣe ẹrí ini wa, titi di irapada
ohun ini Ọlọrun si iyìn ogo rẹ̀.
15 Nitorina emi pẹlu, lẹhin igbati mo ti
gburó igbagbọ́ nyin ninu Jesu Oluwa, ati
ifẹ si gbogbo enia mimọ́,
16 Emi kò simi lati mā dupẹ nitori
nyin, emi ndarukọ nyin ninu adura mi ;
17 Pe ki Ọlọrun Jesu Kristi Oluwa wa,
Baba ogo, ki o le fun nyin li Ẹmí ọgbọ́n
ati ti ifihan ninu ìmọ rẹ̀ :
18 Ki o si fi imọlẹ fun oju ọkàn nyin ;
ki ẹnyin ki o le mọ̀ kili ohun ireti nipa ìpe
rẹ̀ jasi, ati kili ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ ogo ilẹnini rẹ̀
ninu awọn enia mimọ́,
19 Ati kili agbara rẹ̀ ti o tobi julọ si awa
ti o gbagbọ́, gẹgẹ bi iṣẹ ipá agbara rẹ̀,
20 Eyiti o ti ṣiṣẹ ninu Kristi, nigbati o
ti jí i dide kuro ninu okú, ti o si fi i joko
li ọwọ́ ọtún on tikararẹ̀ li ọrun,
21 Ga jù gbogbo ipò ijoye, ati agbara,
ati ipá, ati ọlá nla, ati gbogbo orukọ ti a
npè̀ni, kì iṣe ni kìki aiye yi nikan, ṣugbọn
niti eyiti mbọ̀ pẹlu :
22 O si ti fi ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ rẹ̀, o
si ti fifun u lati jẹ ori lori ohun gbogbo fun
ijọ,
23 Ti iṣe ara rẹ̀, ẹkún ẹniti o kún ohun
gbogbo ninu ohun gbogbo.

## ORI 2.

ẸNYIN li o si ti sọ di àye ẹniti o ti kú
sinu irekọja ati sinu ẹ̀ṣẹ ;
2 Ninu eyiti ẹnyin ti nrìn nigba atijọ
gẹgẹ bi ìwa aiye yi, gẹgẹ bi ọba agbara oju
ọrun : ẹmí na ti nṣiṣẹ nisisiyi ninu awọn
ọmọ alaigbọran :
3 Ninu awọn ẹniti gbogbo wa pẹlu ti ni
ìwa wa nigba atijọ ninu ifẹkufẹ ara wa,
awa nmu ifẹ ara ati ti inu ṣẹ ; ati nipa ẹda
awa si ti jẹ ọmọ ibinu, gẹgẹ bi awọn ẹlo-
miran.
4 Ṣugbọn Ọlọrun, ẹniti iṣe ọlọrọ̀ li ānu,
nipa ifẹ nla rẹ̀ ti o ti fẹ wa,
5 Ani nigbati awa ti kú sinu ẹ̀ṣẹ, o si ti
sọ wa di āye pẹlu Kristi, (nipa ore-ọfẹ ẹni-
ti a ti ngbà nyin là ;)

Digitized by Google

6 O si ti gbé wa soke pọ̀, o si ti mu wa
joko pọ̀ ninu ohun ọrun ninu Kristi Jesu :
7 Pe ni igba aiye ti mbọ̀, ki o le fi ọrọ̀
ore-ọfẹ rẹ̀ hàn lọpọlọpọ niti iṣeun rẹ̀ si wa
nipa Kristi Jesu.
8 Nitoripe nipa ore-ọfẹ li a ti ngbà nyin
là nipa igbagbọ́ ; ati eyini kì iṣe ti ẹnyin
tikara nyin : ẹ̀bun Ọlọrun ni :
9 Kì iṣe nipa ti iṣẹ, ki ẹnikẹni ki o má
bà ṣogo.
10 Nitoripe awa ni iṣẹ ọwọ́ rẹ̀, ti a ti ṣe
ninu Kristi Jesu si iṣẹ rere wọnni, ti Ọlọ-
run ti pèse silẹ, ki awa ki o le ma rìn ninu
wọn.
11 Nitorina ẹ ranti pe, nigba atijọ ẹnyin
ti jẹ Keferi nipa ti ara, awọn ẹniti a npè ni
Alaikọla nipa eyiti a npè ni Ikọla ti a fi
ọwọ́ ṣe nipa ti ara ;
12 Pe li akokò na ti ẹnyin wà laini
Kristi, ẹniti iṣe alejò si anfani awọn ọlọ̀tọ
Israeli, ati àjeji kuro ninu ileri majẹmu
wọnni, ẹnyin wà laini ireti, ati laini Ọlọ-
run li aiye :
13 Ṣugbọn nisisiyi ninu Kristi Jesu
ẹnyin ti o ti jìna réré nigba atijọ li a mu
sunmọ tosi, nipa ẹ̀jẹ Kristi.
14 Nitoripe on ni alafia wa, ẹniti o ti ṣe
mejeji li ọkan, ti o si ti wó ogiri ikele nì
palẹ lãrin wa ;
15 O si ti pa ọtá nì run ninu ara on ti-
kararẹ̀, ani ofin aṣẹ wọnni ti o wà nipa
idasilẹ ; ki o le dá ọkọnrin titun kan ninu
on tikararẹ̀ lati inu meji wá, bẽni nṣe ìlaja;
16 Ati ki o le mu awọn mejeji ba Ọlọrun
làja ninu ara kan nipa agbelebu, o si ti pa
ọtá na kú ninu on tikararẹ̀ :
17 O si ti wá o nwasu alafia fun ẹnyin ti
o ti jìna rere, ati fun awọn ti o ti sunmọ
tosi.
18 Nitoripe nipasẹ rẹ̀ li awa mejeji ti li
ọ̀na nipa Ẹmí kan sọdọ Baba.
19 Njẹ nitorina ẹnyin kì iṣe alejò ati
atipo mọ́, ṣugbọn àjumọ jẹ ọlọ̀tọ pẹlu awọn
enia mimọ́, ati awọn arãle Ọlọrun ;
20 A si ngbé nyin ró lori ipilẹ awọn
Aposteli, ati awọn woli, Jesu Kristi tikara-
rẹ̀ ni pàtaki okuta igun ile ;
21 Ninu ẹniti a fi tẹyẹtẹyẹ ṣiṣẹ gbogbo
ile na ṣọkan pọ̀ ti ndàgba soke fun tempili
mimọ́ kan ninu Oluwa :
22 Ninu ẹniti a ngbé nyin ró pẹlu fun
ibujoko Ọlọrun nipa Ẹmí.

## ORI 3.

NITORI eyina, emi Paulu, ondè Jesu
Kristi fun ẹnyin Keferi,
2 Bi ẹnyin ba ti gburó iṣẹ ipinfunni ore-
ọfẹ Ọlọrun, ti a fifun mi si nyin :
3 Bi o ti ṣepe nipa ifihan li o ti fi ohun
ijinlẹ nì hàn fun mi ; (gẹgẹ bi mo ti kọwe
ọ̀rọ diẹ niṣãju,
4 Nigbati ẹnyin ba kà a, nipasẹ eyi ti
ẹnyin o fi moye ìmọ mi ninu ohun ijinlẹ
Kristi,)
5 Eyiti a kò ti fihàn awọn ọmọ enia ri
lati irandiran miran gbogbo, gẹgẹ bi a ti fi
wọn hàn nisisiyi fun awọn Aposteli ati
awọn woli mimọ́ nipa ti Ẹmí ;
6 Ki awọn Keferi ki o le di àjumọjogun,
ki nwọn ki o si le di ara kanna, ati alaba-
pin ileri rẹ̀ ninu Kristi nipa ihin-rere :
7 Nipasẹ eyiti a fi mi ṣe iranṣẹ, gẹgẹ bi
ẹ̀bun ore-ọfẹ Ọlọrun ti a fifun mi, nipa iṣẹ
agbara rẹ̀.
8 Ani fun emi, ọmọ-ẹhin ti o kereju
ninu gbogbo awọn enia mimọ́, li a fi ore-
ọfẹ yi fun, ki emi ki o le ma wasu awamá-
ridi ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ Kristi larin awọn Keferi ;
9 Ati lati fihàn gbogbo enia ohun ti ìda-
pọ ohun ijinlẹ na jasi, eyiti a ti fi pamọ́
lọdọ Ọlọrun lati igba ọjọ ìwa, ẹniti o da
ohun gbogbo nipa Jesu Kristi :
10 Nitori ki a le fi ọ̀pọlọpọ onirũru
ọgbọ́n Ọlọrun hàn nisisiyi fun awọn ijoye,
ati awọn alagbara ti mbẹ li ọrun, nipasẹ ijọ.
11 Gẹgẹ bi ipinnu ainipẹkun na ti o ti
pinnu ninu Kristi Jesu Oluwa wa :
12 Nipasẹ ẹniti awa ti ni igboiya, ati
ọ̀na pẹlu igbẹkẹle nipa igbagbọ́ lọdọ rẹ̀.
13 Nitorina mo bẹ̀ nyin ki ãrẹ̀ ki o máṣe
mu nyin nitori gbogbo wahalà mi nitori
nyin, ti iṣe ogo nyin.
14 Nitori idi eyi ni mo ṣe nfi ẽkun mi
kunlẹ lọdọ Baba Jesu Kristi Oluwa wa,
15 Lọdọ ẹniti a npè gbogbo idile ti mbẹ
li ọrun ati li aiye li orukọ,
16 Ki on ki o le fifun nyin, gẹgẹ bi
ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ ogo rẹ̀, lati fi ipá mu nyin lara
le nipa Ẹmí rẹ̀ niti ọkọnrin inu ;
17 Ki Kristi ki o le mã gbé ọkàn nyin
nipa igbagbọ́ ; pe bi a ti fi ẹsẹ nyin mulẹ,
ti a si fi idi nyin kalẹ ninu ifẹ,
18 Ki ẹnyin ki o le mọ̀ pẹlu gbogbo enia
mimọ́, ohun ti ibú, ati gigùn, ati jijìn, ati
giga na jasi ;
19 Ati lati mọ̀ ifẹ Kristi ti o pọ̀ju ìmọ
gbogbo lọ, ki ẹnyin ki o le kún fun gbogbo
ẹ̀kún Ọlọrun.
20 Nisisiyi fun ẹniti o le ṣe lọpọlọpọ jù
gbogbo eyiti a mbère, tabi ti a nrò lọ, gẹgẹ
bi agbara ti nṣiṣẹ ninu wa,
21 On ni ki a ma fi ogo fun ninu ijọ ati



Digitized by Google

ninu Kristi Jesu lati irandiran gbogbo, aiye ainipẹkun. Amin.

## ORI 4.

NITORINA emi ondè nipa ti Oluwa, mbẹ̀ nyin pe, ki ẹnyin ki o mã rìn bi o ti yẹ fun ìpe na nipasẹ eyiti a pè nyin,

2 Pẹlu irẹlẹ ọkàn gbogbo ati inu tutù, pẹlu ipamọra, ki ẹnyin ki o si mã fi sũru gbà ọmọnikeji nyin nipa ifẹ:

3 Ki ẹ si ma rọju lati pa iṣọkan ẹmí mọ́ ni ìdipọ alafia.

4 Nitori ara kan ni mbẹ, ati Ẹmí kan, gẹgẹ bi a ti pè nyin niti ireti kan ti a pè nyin si;

5 Oluwa kan, igbagbọ́ kan, baptismu kan,

6 Ọlọrun kan ati Baba gbogbo, ẹniti o wà lori gbogbo, ati nipa gbogbo, ati ninu nyin gbogbo.

7 Ṣugbọn olukuluku wa li a fi ore-ọfẹ fun gẹgẹ bi ìwọn ẹ̀bun Kristi.

8 Nitorina o wipe, Nigbati o ti gòke lọ si ibi giga, o di awọn igbekun ni igbekun lọ, o si ti fi ẹ̀bun fun enia.

9 (Niti pe o gòke lọ si ọrun, kini rè, bikoṣe pe on pẹlu ti tète sọkalẹ lọ si ìha isalẹ aiye?

10 Ẹnikan na ti o ti sọkalẹ li o si ti gòke lọ si ibi ti o ga jù gbogbo ọrun lọ, ki o le kún ohun gbogbo.)

11 O si ti fifun awọn ẹlomiran, iṣẹ aposteli; ati fun awọn ẹlomiran, iṣẹ woli; ati fun awọn ẹlomiran, iṣẹ efangelisti; ati fun awọn ẹlomiran, iṣẹ olusọ-agutan ati iṣẹ olukọni;

12 Lati ṣe awọn enia mimọ́ li aṣepé, fun iṣẹ isin alufa, fun idagbasoke ara Kristi:

13 Titi gbogbo wa o fi wá sinu iṣọkan igbagbọ́, ati sinu ìmọ Ọmọ Ọlọrun, si ọkọnrin pipé kan, si oṣuwọn ọdún àgba ti o kún niti Kristi:

14 Lati isisiyi lọ ki awa ki o máṣe jẹ ewe mọ́, ẹniti a o mã tì siwa tì sẹhin, ati ti a o si mã fi gbogbo afẹfẹ ẹkọ́kẹkọ gbá kiri, nipa itanjẹ enia, ati ọgbọ́n arekereke nipasẹ eyiti nwọn fi mba ni buba fun itanjẹ;

15 Ṣugbọn ki a mã sọ otitọ ni ifẹ, ki a le mã dàgbasoke ninu rẹ̀ li ohun gbogbo, ẹniti iṣe Ori, ani Kristi:

16 Lati ọdọ ẹniti a fi tẹyẹtẹyẹ so gbogbo ara ṣọkan pọ̀, ti o si fi ara mọra nipa eyiti a fi nkún gbogbo orike, gẹgẹ bi iṣẹ aitase na ninu oṣuwọn ni ìha gbogbo, lati mã mu ara na bisi i fun idagbasoke on tikararẹ̀ ninu ifẹ.

17 Njẹ eyi ni mo wi, ti mo si njẹri niti Oluwa pe, lati isisiyi lọ ki ẹnyin ki o máṣe rìn bi awọn Keferi miran ti nrìn, ninu ìro asan inu wọn.

18 Oyé awọn ẹniti o ṣe òkunkun, ti a si ti sọdi àjeji si ìwa-bi-Ọlọrun nipa aimọ̀ ti mbẹ ninu wọn, nitori lile àiya wọn:

19 Awọn ẹniti àiya wọn le rekọja, ti nwọn si ti fi ara wọn fun wọ̀bia, lati ma fi ojukòkoro ṣiṣẹ ìwa-ẽri gbogbo.

20 Ṣugbọn a kò fi Kristi kọ́ nyin bẹ̃;

21 Bi ẹnyin ba ti gbohùn rẹ̀ nitõtọ, ti a si ti kọ́ nyin lati ọdọ rẹ̀ wá, gẹgẹ bi otitọ ti mbẹ ninu Jesu:

22 Pe ki ẹ bọ́ ara ìwa atijọ silẹ li apakan nipa ogbologbo ọkọnrin nì, eyiti o dibajẹ gẹgẹ bi ifẹkufẹ nipa ẹ̀tan;

23 Ki ẹ si di titun ni inu nyin nipa ti ẹmí;

24 Ki ẹ si gbé ọkọnrin titun nì wọ̀, ẹniti a da li ododo nipa ti Ọlọrun ati li otitọ ìwa mimọ́.

25 Nitorina ẹ fi eke ṣiṣe silẹ, ki olukuluku nyin ki o ma sọ otitọ fun ọmọnikeji rẹ̀: nitori ẹ̀ya ara ọmọnikeji wa li awa iṣe.

26 Bi ẹnyin ba binu, ẹ má si ṣẹ̀: ẹ máṣe jẹ ki õrùn wọ̀ sori ibinu nyin:

27 Ẹ má si ṣe fi àye fun Èṣu.

28 Ki ẹniti o ti njale ri ki o máṣe jale mọ́: ṣugbọn ki o kuku mã ṣe lãlã, ki o mã fi ọwọ́ rẹ̀ ṣiṣẹ ohun ti o dara, ki on ki o le ni lati pín fun ẹniti o ṣe alaini.

29 Ẹ máṣe jẹ ki ọ̀rọ idibajẹ ti ẹnu nyin jade mọ́, ṣugbọn eyiti o dara lati mã lò fun ẹkọ́ ti o li ère, ki o le mã ṣiṣẹ ore-ọfẹ fun awọn ti o gbọ́.

30 Ẹ má si ṣe mu Ẹmí Mimọ́ Ọlọrun binu, ẹniti a fi ṣe èdidi nyin dè ọjọ idande.

31 Ẹ jẹ ki gbogbo ìwa kikorò, ati ibinu, ati irunu, ati ariwo, ati isọ̀rọ buburu ki a mu u kuro lọdọ nyin, pẹlu gbogbo arankàn:

32 Ẹ si ma ṣore fun ọmọnikeji nyin, ẹ ni iyọ́nu, ẹ ma darijì ọmọnikeji nyin, gẹgẹ bi Ọlọrun nitori Kristi ti darijì nyin.

## ORI 5.

NITORINA ẹ mã ṣe ọmọ lẹhin Ọlọrun bi awọn ọmọ ọ̀wọn;

2 Ẹ si ma rìn ninu ifẹ, gẹgẹ bi Kristi pẹlu ti fẹ wa, ti o si fi ara rẹ̀ fun wa bi ọrẹ ẹ̀bun ati ẹbọ fun Ọlọrun fun õrùn didun.

3 Ṣugbọn àgbere, ati gbogbo ìwa-ẽri, tabi ojukòkoro, ki a máṣe darukọ rẹ̀ larin nyin mọ́, bi awọn ẹniti o di enia mimọ́;

4 Ibã ṣe ìwa ọ̀bun, ati isọ̀rọ aṣiwère,

Digitized by Google

tabi iṣẹ̀fẹ, awọn ti kò tọ́: ṣugbọn ẹ kuku
mã dupẹ.
5 Nitori ẹnyin mọ̀ eyi pe, kò si panṣaga,
tabi alaimọ́ enia, tabi olojukòkoro, ti iṣe
olubọriṣa, ti yio ni ini kan ni ijọba Kristi
ati ti Ọlọrun.
6 Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni fi ọ̀rọ asan tàn
nyin jẹ: nitori nipasẹ nkan wọnyi ibinu
Ọlọrun mbọ̀ wá sori awọn ọmọ alaigbọran.
7 Nitorina ẹ máṣe jẹ alajọpin pẹlu wọn.
8 Nitori ẹnyin ti jẹ òkunkun lẹ̀kan,
ṣugbọn nisisiyi ẹnyin di imọlẹ nipa ti Olu-
wa: ẹ mã rìn gẹgẹ bi awọn ọmọ imọlẹ:
9 (Nitori eso Ẹmí wà niti iṣore gbogbo,
ati ododo, ati otitọ;)
10 Ẹ mã wadi ohun ti iṣe itẹwọgbà fun
Oluwa.
11 Ẹ má si ṣe ba aileso iṣẹ òkunkun
kẹgbẹ pọ̀, ṣugbọn ẹ kuku ma ba wọn wi.
12 Nitoripe itiju tilẹ ni lati ma sọ̀rọ
nkan wọnni ti nwọn nṣe nikọ̀kọ.
13 Ṣugbọn ohun gbogbo ti a mba wi li
a fihàn nipa imọlẹ: nitori ohunkohun ti o
ba fi ara hàn ni iṣe imọlẹ.
14 Nitorina li o ṣe wipe, Jí iwọ ẹniti o
sùn, ki o si jinde kuro ninu okú, Kristi
yio si fun ọ ni imọlẹ.
15 Nitorina ẹ kiyesi lati mã rìn ni ìwa
pipé, kì iṣe bi awọn alaimoye, ṣugbọn bi
awọn ọlọ́gbọn,
16 Ẹ mã ṣe irapada ìgba, nitori buburu
li awọn ọjọ.
17 Nitorina ki ẹ máṣe alaimoye, ṣugbọn
ẹ mã moye ohun ti ifẹ Oluwa jasi.
18 Ẹ má si ṣe kún fun ọti-waini, ninu
eyiti aṣeju wà; ṣugbọn ẹ kún fun Ẹmí;
19 Ẹ si mã ba ara nyin sọ̀rọ ninu orin
mimọ́, ati orin iyìn, ati orin nipa ti ẹmí, ẹ
mã kọrin, ki ẹ si mã fi ọgbọ́n kọrin li àiya
nyin si Oluwa;
20 Ẹ mã dupẹ nigbagbogbo nitori ohun
gbogbo lọwọ Ọlọrun ati Baba li orukọ Jesu
Kristi Oluwa wa;
21 Ẹ mã foribalẹ fun ara nyin ni ìbẹru
Ọlọrun.
22 Ẹnyin aya, ẹ mã tẹriba fun awọn
ọkọ nyin, gẹgẹ bi si Oluwa.
23 Nitoripe ọkọ ni iṣe ori aya, gẹgẹ bi
Kristi ti ṣe Ori ijọ enia rẹ̀: on si ni Olu-
gbala ara.
24 Nitorina gẹgẹ bi ijọ ti tẹriba fun
Kristi, bẹ̃ni ki awọn aya ki o mã ṣe si ọkọ
wọn li ohun gbogbo.
25 Ẹnyin ọkọ, ẹ fẹ aya nyin, gẹgẹ bi
Kristi pẹlu ti fẹ ijọ enia rẹ̀, ti o si fi ara rẹ̀
fun u;
26 Ki on ki o le sọ ọ di mimọ́ ki o si le
fi ìwẹ omi wẹ̀ ẹ mọ́ nipa ọ̀rọ na,
27 Ki on ki o le mu u wá fun ara rẹ̀ ni
ijọ ti o li ogo, li aini abawọn, tabi ikiweje,
tabi irú nkan bawọnni; ṣugbọn ki o le mọ́
ati li aini àbuku.
28 Bẹ̃li o tọ́ ki awọn ọkọnrin ki o mã fẹ
awọn aya wọn gẹgẹ bi ara awọn tikara wọn.
Ẹniti o ba fẹ aya rẹ̀, o fẹ on tikararẹ̀.
29 Nitori kò si ẹnikan ti o ti korira ara
rẹ̀; bikoṣe pe ki o mã bọ́ ọ ki o si mã kẹ́ ẹ,
gẹgẹ bi Oluwa ti nkẹ́ ti o si mbọ́ ijọ rẹ̀:
30 Nitoripe awa li ẹ̀ya ara rẹ̀, ẹran ara
rẹ̀, ati egungun ara rẹ̀.
31 Nitori eyi li ọkọnrin yio ṣe fi baba
ati iya rẹ̀ silẹ, on o si dàpọ mọ́ aya rẹ̀,
awọn mejeji a si di ara kan.
32 Ohun ijinlẹ nla li eyi: ṣugbọn emi
nsọ ti Kristi on ijọ rẹ̀.
33 Ṣugbọn ki olukuluku nyin ki o fẹ
aya rẹ̀ bẹ̃ gẹgẹ bi on tikararẹ̀; ṣugbọn ki
aya ki o bù ọlá fun ọkọ rẹ̀.

## ORI 6.

ENYIN ọmọ, ẹ tẹriba fun awọn õbi nyin
ninu Oluwa: nitoripe eyi li o tọ́.
2 Bọ̀wọ fun baba ati iya rẹ; eyi ti iṣe
ofin ikini pẹlu ileri;
3 Ki o le ba dara fun ọ, ati ki iwọ ki o
le wà pẹ li aiye.
4 Ati ẹnyin baba, ẹ máṣe mu awọn ọmọ
nyin binu: ṣugbọn ẹ mã tọ́ wọn ninu ẹkọ́
ati ìbẹru Oluwa:
5 Ẹnyin ẹrú, ẹ foribalẹ fun awọn ti iṣe
oluwa nyin gẹgẹ bi ti ara, pẹlu ìbẹru ati
iwariri, ni otitọ ọkàn nyin, gẹgẹ bi ẹnipe
si Kristi;
6 Ki iṣe li arojuṣe bi awọn ti nwù enia;
ṣugbọn gẹgẹ bi awọn ẹrú Kristi, ẹ mã ṣe
ifẹ Ọlọrun tinutinu;
7 Ni fifi inu-rere ṣe iṣẹ, bi ẹnipe si Olu-
wa, kì si iṣe si enia:
8 Ki ẹ si mọ̀ pe, ohunkohun rere ti enia-
kan ba ṣe, on na ni yio si gbà lọwọ Oluwa,
ibã ṣe ẹrú, tabi omnira.
9 Ati ẹnyin oluwa, ẹ ṣe bẹ̃ gẹgẹ si wọn,
ẹ mã fà ọwọ ìkilọ nyin sẹhin: ki ẹ si mọ̀
pe Oluwa nyin mbẹ li ọrun pẹlu; kò si si
ojusaju enia lọdọ rẹ̀.
10 Li akotan, ará mi, ẹ jẹ alagbara ninu
Oluwa, ati ninu ipá agbara rẹ̀.
11 Ẹ mu gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀, ki
ẹnyin ki o le duro dè arekereke Eṣu.
12 Nitoripe kì iṣe ẹ̀jẹ ati ẹran-ara li awa
mba jijakadi, ṣugbọn awọn ijoye, awọn

Digitized by Google

alagbara, awọn olori ibi òkunkun aiye yí,
ati awọn ẹmí buburu ni oju ọrun.
13 Nitorina ẹ mu gbogbo ihamọra Ọlọ-
run wọ̀, ki ẹ le kọjujasi ọjọ buburu lati
duro, nigbati ẹnyin ba ti ṣe gbogbo wọn
tan.
14 Ẹ duro nitorina, bi awọn ti a ti fi
àmure otitọ dì lẹgbẹ, ki ẹ si di awo-àiya
ododo nì mọra;
15 Ki a si fi imura ihin-rere alafia wọ̀
ẹsẹ nyin ni bàta;
16 Li akotan, ẹ mu apata igbagbọ́, ni-
pasẹ eyiti ẹnyin o fi le mã paná gbogbo ọfà
iná ẹni buburu nì.
17 Ki ẹ si mu aṣibori irin igbala, ati idà
Ẹmí nì, ti iṣe ọ̀rọ Ọlọrun:
18 Ẹ mã fi igbagbogbo gbadura ni gbo-
gbo adura ati ẹ̀bẹ nipa ti Ẹmí, kí ẹ si mã
ṣọra sibẹ̀ pẹlu iduro-ṣinṣin gbogbo, ati ẹ̀bẹ
fun gbogbo enia mimọ́;
19 Ati fun mi, ki a le fi ohùn fun mi, ki
emi ki o le mã fi igboiya yà ẹnu mi, lati
mã fi ohun ijinlẹ ihin-rere hàn,
20 Nitori eyiti emi iṣe onṣẹ ninu ẹ̀wọn:
ki emi ki o le mã fi igboiya sọ̀rọ ninu rẹ̀,
gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati mã sọ.
21 Ṣugbọn ki ẹnyin pẹlu ki o le mọ̀
ọ̀ran mi, ati bi mo ti nṣe si, Tikiku ara-
kọnrin olufẹ ati iranṣẹ olõtọ niti Oluwa,
yio mu nyin mọ̀ ohun gbogbo:
22 Ẹniti mo rán si nyin nitori eyi kanna,
ki ẹ le mọ̀ ọ̀ran wa, ati ki on ki o le tù
nyin li ọkàn.
23 Alafia fun awọn ará, ati ifẹ pẹlu igba-
gbọ́, lati ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati Jesu
Kristi Oluwa.
24 Ki ore-ọfẹ wà pẹlu gbogbo awọn ti
nfi inu funfun fẹ Jesu Kristi Oluwa wa.
Amin.

A kọ ọ lati Romu lọ si awọn ara Efesu lati ọwọ́ Tikiku.

---

EPISTELI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA FILIPPI.

ORI 1.

PAULU ati Timoteu, awọn iranṣẹ Jesu
Kristi, si gbogbo awọn enia mimọ́ ni-
nu Kristi Jesu ti o wà ni Filippi, pẹlu
awọn biṣopu ati awọn diakoni:
2 Ore-ọfẹ si nyin, ati alafia, lati ọdọ
Ọlọrun Baba wa, ati Jesu Kristi Oluwa
wá.
3 Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun mi ninu gbogbo
ṣiṣe iranti mi fun nyin,
4 Emi nfi ayọ̀ bẹ̀bẹ nigbagbogbo ninu
gbogbo adura mi fun gbogbo nyin,
5 Nitori ìdapọ nyin ninu ihin-rere lati
ọjọ ikini wá titi fi di isisiyi;
6 Oju mi sá ti da si ohun kanna yi, pe
ẹniti o ti bẹ̀rẹ iṣẹ rere ninu nyin, yio si
pari rẹ̀ titi fi di ọjọ Jesu Kristi:
7 Gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati rò eyi fun
gbogbo nyin, nitori ti ẹnyin ni mi li àiya
nyin; niwọn bi o ti ṣepe nipa ìde mi, ati
nipa àbo mi ati ifẹsẹ-mulẹ ihin-rere, gbo-
gbo nyin ni iṣe alabapin ninu ore-ọfẹ pẹlu
mi.
8 Nitoripe Ọlọrun li ẹlẹri mi, bi mo ti
nṣafẹri nyin to gidigidi ninu iyọ́nu Jesu
Kristi.
9 Emi si ngbadura nitori eyi pe, ki ifẹ
nyin ki o le ma pọ̀ si i lọpọlọpọ ninu ìmọ
ati ninu ọgbọ́n gbogbo;
10 Ki ẹnyin ki o le dán ohun ti o yàtọ
wò; ki ẹ le jasi pipé ati alailẹṣẹ titi fi di
ọjọ Jesu Kristi;
11 Ki ẹ le kún fun eso ododo, ti iṣe
nipa Jesu Kristi, fun ogo ati iyìn Ọlọrun.
12 Ṣugbọn emi nfẹ ki oyé ki o yé nyin,
ará, pe nkan wọnni ti o de bá mi, o kuku
jasi ti igbéleke ihin-rere;
13 Bẹ̃ni ìde mi nitori Kristi farahàn ni
gbogbo àgbala Kesari, ati ni ibomiran
gbogbo;
14 Ati ọ̀pọlọpọ awọn arakọnrin ninu

Digitized by Google

Oluwa, li o ni igbękęle nipa ìde mi, nwọn
si nfi igboiya sọ ọ̀rọ na gidigidi li aibẹ̀ru.
15 Nitõtọ awọn ẹlomiran tilẹ nwasu
Kristi nipa ilara ati ìja; ati awọn ẹlomiran
pẹlu nipa ifẹ inu-rere:
16 Awọn ọkan nfi ìja wasu Kristi, kì işe
tinutinu, nwọn ngbìro lati fi ipọnju kún
ìde mi:
17 Şugbọn awọn ẹlomiran nipa ifẹ, nitori
ti nwọn mọ̀ pe a fi mi şe àbo ihin-rere.
18 Njẹ kini? bikoşepe nibi gbogbo, iba
şe nipa aşehàn, tabi li otitọ, bẽli a nwasu
Kristi; emi si nyọ̀ nitorina, nitõtọ, emi o
si ma yọ̀.
19 Nitoriti mo mọ̀ pe eyi ni o jasi igbala
fun mi nipa adura nyin, ati ifikún Ẹmí
Jesu Kristi,
20 Gẹgẹ bi afojusọ̀na ati ireti mi tinutinu,
pe ki oju ki o máşe tì mi li ohunkohun,
şugbọn pe ni igboiya gbogbo, bi o ti wà
nigbagbogbo ri, gẹgẹ bẽli a o si ma gbé
Kristi ga li ara mi nisisiyi pẹlu, iba şe
nipa ìye, tabi nipa ikú.
21 Nitoripe wiwà li ãye mi ti Kristi ni,
ikú si li èrè fun mi.
22 Şugbọn bi emi ba wà li ara, eyi li
èrè işẹ mi: şugbọn eyi ti emi iba yàn, emi
kò mọ̀.
23 Nitoripe emi mbẹ ni iye-meji, mo ni
ifẹ ati-lọ, ki emi ki o le wà lọdọ Kristi; ti
o darajù:
24 Şugbọn o jasi èrè jù fun nyin bi mo
ba wà li ara.
25 Bi mo si ti ni igbẹkẹle yi, mo mọ̀ pe
emi o duro, emi o si mã ba gbogbo nyin
gbé fun igbéleke ati ayọ̀ igbagbọ́ nyin
lọpọlọpọ;
26 Ki ayọ̀ nyin ki o le di pipọ gidigidi
nipa Jesu Kristi fun mi nipa itúnpada wá
mi sọdọ nyin.
27 Kìki ki ẹ sá jẹ ki ìwa-aiye nyin ki o
ma ri gẹgẹ bi ihin-rere Kristi: pe yala bi
mo tilẹ wá wò nyin, tabi bi emi kò si,
ki emi ki o le ma gburó işe nyin, pe ẹnyin
duroşinşin ninu Ẹmí kan pẹlu ọkàn kan,
ẹnyin jùmọ njagun nitori igbagbọ́ ihinrere;
28 Ki ẹnyin ki o máşe bẹ̀ru nitori awọn
ọtá nyin li ohunkohun: eyiti işe àmi kan
fun iparun wọn ti o daniloju, şugbọn eyiti
işe igbala fun nyin, ati eyini ni lati ọwọ́
Ọlọrun wá.
29 Nitoripe ẹnyin li a fifun nitori Kristi,
kì işe lati gbà a gbọ́ nikan, şugbọn lati
jìya nitori rẹ̀ pẹlu;
30 Ẹnyin si ni ìja kanna ti ẹnyin ti ri
ninu mi, ti ẹnyin si gbọ́ nisisiyi pe o wà
ninu mi.

## ORI 2.

NITORINA bi iyanju kan ba wà nipa ti
Kristi, bi itunu kan ba wà nipa ti
ifẹ, bi ìdapọ kan ba wà nipa ti Ẹmí, bi iyọ́nu
ati irọ̀nu ba wà,
2 Ẹ mu ayọ̀ mi kún, ki ẹ si jẹ oninu
kanna, ki ẹnyin ni ifẹ kanna, ki ìmọ nyin
ki o şọkan, ki ẹ si jẹ oninu kan.
3 Ẹ máşe fi ìja, tabi ogo asan şe ohunkohun:
şugbọn ni irẹlẹ ọkàn ki olukuluku
enia ki o mã buyìn fun ẹnikeji rẹ̀ jù fun
ontikararẹ̀ lọ.
4 Ki olukuluku ki o máşe kiyesi kìki
ohun tirẹ̀, şugbọn olukuluku ohun ti ẹlomiran.
5 Ẹ ni ọkàn yi ninu nyin, eyi ti o ti wà
pẹlu ninu Kristi Jesu:
6 Ẹniti o tilẹ jẹ aworan Ọlọrun, ti kò ka
a si iwọra lati ba Ọlọrun dọgba.
7 Şugbọn o bọ́ ogo rẹ̀ silẹ, o si mu awọran
ẹrú, a si bi i ni ìri enia.
8 Nigbati a si ti ri i ni ìri gẹgẹ bi ti
enia, o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, o si tẹriba titi di oju
ikú, ani ikú ori agbelebu.
9 Nitorina Ọlọrun si ti gbé e le ibi gigagiga
pẹlu, o si ti fi orukọ kan fun u ti o
bori gbogbo orukọ:
10 Pe, li orukọ Jesu ni ki gbogbo ẽkun
ki o ma kunlẹ, awọn ẹniti mbẹ li ọrun, ati
awọn ẹniti mbẹ ni ilẹ, ati awọn ẹniti mbẹ
nisalẹ ilẹ;
11 Ati pe ki gbogbo ahọn ki o mã jẹwọ
pe, Jesu Kristi ni Oluwa, fun ogo Ọlọrun
Baba.
12 Nitorina ẹnyin olufẹ mi, bi ẹnyin ti
ngbagbọ́ nigbagbogbo, kì işe nigbati mo
wà lọdọ nyin nikan, şugbọn pẹlupẹlu nisisiyi
nigbati emi kò si, ẹ mã şişẹ igbala
nyin jade ni ìbẹru ati iwarìri.
13 Nitoripe Ọlọrun ni nşişẹ mejeji ninu
nyin, lati fẹ ati lati şe nipa ifẹ inu rere rẹ̀.
14 Ẹ mã şe ohun gbogbo li aisi ìkùnsinu
ati ìja:
15 Ki ẹnyin ki o le jẹ alailẹgàn ati alailẹşẹ,
bi awọn ọmọ Ọlọrun, alainibawi larin
orilẹ-ède oniwà wíwọ ati arekereke enia,
larin ẹniti ẹnyin ntàn li aiye bi imọlẹ;
16 Ẹ mã di ọ̀rọ ìye mu şinşin; ki emi ki
o le yọ̀ li ọjọ Kristi pe emi kò sáre lasan,
emi kò si şe lãlã lasan.
17 Ani, bi a tilẹ tú mi dà sori ẹbọ ati işẹ
igbagbọ́ nyin, mo yọ̀, mo si mba gbogbo
nyin yọ̀ pẹlu.

Digitized by Google

18 Nitori eyi kanna ni ki ẹnyin ki o ma
yọ̀, ki ẹ si mã ba mi yọ̀ pẹlu.
19 Ṣugbọn mo ni reti nipa Jesu Oluwa,
lati rán Timoteu si nyin ni lọ̃lọ̀yi, ki emi
pẹlu ki o le wà ni inu didùn, nigbati mo
ba gburó ijoko nyin.
20 Nitori emi kò ni oninu kan ti o dabi
rẹ̀, ẹniti yio ma fi tinutinu ṣe aniyan nyin.
21 Nitori gbogbo wọn ni ntọju nkan ti
ara wọn, kì iṣe nkan ti iṣe ti Jesu Kristi.
22 Ṣugbọn ẹnyin ti mọ̀ ọ dajudaju, pe
gẹgẹ bi ọmọ lọdọ baba rẹ̀, bẹ̃li o si ti mba
mi ṣiṣẹ pọ̀ ninu ihin-rere.
23 Nitorina on ni mo tanma lati rán si
nyin nisisiyi, nigbati mo ba woye bi yio ti
ri fun mi.
24 Ṣugbọn mo gbẹkẹle Oluwa, pe emi
tikarami pẹlu yio wá nisisiyi.
25 Ṣugbọn mo rò pe anfani ni lati rán
Epafroditu arakọnrin mi si nyin, ati ọgba
mi ninu iṣẹ, ati ọmọ-ogun ẹgbẹ mi, ṣugbọn
iranṣẹ nyin, ati ẹniti nṣe iranṣẹ fun mi
ninu aini mi.
26 Nitoriti ọkàn rẹ̀ fà si gbogbo nyin, o
si kún fun ibinujẹ, nitori ti ẹnyin ti gbọ́
pe on ti ṣe aisan.
27 Nitõtọ li o ti ṣe aisan titi de oju ikú :
ṣugbọn Ọlọrun ti ṣãnu fun u ; kì si iṣe fun
on nikan, ṣugbọn fun mi pẹlu, ki emi ki o
máṣe ni ibinujẹ lori ibinujẹ.
28 Nitorina ni mo ṣe fi ọ̀pọlọpọ ayọ̀ rán
a si nyin, pe nigbati ẹnyin ba si tún ri i,
ki ẹnyin ki o le yọ̀, ati ki ibinujẹ mi ki o
le mọ̀ niwọn.
29 Nitorina ẹ fi ayọ̀ pipọ gbà a nipa ti
Oluwa ; ki ẹ si ma bù ọlá fun irú awọn ẹni
bẹ̃ :
30 Nitoripe nitori iṣẹ Kristi li o ṣe sun-
mọ ẹnu-ọ̀na ikú, ti kò si kà ẹmí ara rẹ̀ si,
lati mu aito iṣẹ nyin kún fun mi.

## ORI 3.

LI akotan, ará, ẹ mã yọ̀ ninu Oluwa. Kì
iṣe ohun ibinujẹ fun mi lati kọwe
ohun kanna si nyin, ṣugbọn fun nyin o jasi
ailewu.
2 Ẹ mã kiyesi awọn ajá, ẹ mã kiyesi
awọn oluṣe buburu, ẹ mã kiyesi awọn onilà.
3 Nitori awa ni onilà, ti nsìn Ọlọrun
nipa ti Ẹmí, awa si nyọ̀ ninu Kristi Jesu,
awa kò si ni igbẹkẹle nipa ti ara.
4 Pẹlupẹlu emi iba ni igbẹkẹle nipa ti
ara. Bi ẹnikẹni ba rò pe on ni ibiti on iba
gbẹkẹle nipa ti ara, emi li o jù :
5 Ẹniti a kọ-nilà ni ijọ kẹjọ, lati inu
kukuté Israeli wá, lati inu ẹ̀ya Benjamini,
Heberu lati inu Heberu wá ; nipa ti ofin,
Farisi li emi ;
6 Niti itara, emi nṣe inunibini si ijọ ;
niti ododo ti o wà ninu ofin, mo wà li ailẹgan.
7 Ṣugbọn ohunkohun ti o ti jasi èrè fun
mi, awọn ni mo ti kà si òfo nitori Kristi.
8 Nitõtọ laiṣe ani-ani mo si kà ohun
gbogbo si òfo nitori itayọ ìmọ Kristi Jesu
Oluwa mi : nitori ẹniti mo ti ṣòfo ohun
gbogbo, mo si kà wọn si igbẹ́, ki emi ki o
le jère Kristi,
9 Ki a le bá mi ninu rẹ̀, li aini ododo ti
emi tikarami, ti iṣe ti ofin, ṣugbọn eyi ti
iṣe ti Kristi nipa igbagbọ́, ododo ti Ọlọrun
nipa igbagbọ́ :
10 Ki emi ki o le mọ̀ ọ, ati agbara ajinde
rẹ̀, ati alabapin ninu ìya rẹ̀, nigbati mo ba
faramọ ikú rẹ̀ ;
11 Bi o le ṣe ki emi ki o le de ibi ajinde
awọn okú.
12 Kì iṣe bi ẹnipe emi tilẹ ti de ibẹ̀ na,
bẹ̃li emi kò ti idi pipé : ṣugbọn emi nlepa
bọ̀ lẹhin, bi ọwọ́ mi yio le tẹ̀ èrè na, nitori
eyiti a ti di mi mu pẹlu, lati ọdọ Kristi
Jesu wá.
13 Ará, emi kò kà ara mi si ẹniti ọwọ́
rẹ̀ ti tẹ̀ ẹ na : ṣugbọn ohun kan yi li emi
nṣe, emi ngbagbé nkan wọnni ti o wà
lẹhin, mo si nnọ̀gà wò nkan wọnni ti o wà
niwaju,
14 Emi nlepa lati de ibi àmi nì fun ère
ìpe giga Ọlọrun ninu Kristi Jesu.
15 Nitorina, iye awa ti iṣe ẹni pipé, ẹ jẹ
ki ama ṣe itọju bẹ̃ : bi ẹnyin ba si nti ipa
ọ̀na miran ṣe itọju ohunkohun, Ọlọrun yio
fi eyi na hàn nyin pẹlu.
16 Ṣugbọn, nibiti a ti de na, ẹ jẹ ki ama
rìn nipa ìwọn kanna, ẹ jẹ ki ama ṣe itọju
ohun kanna.
17 Ará, ẹ mã ṣe ọmọ lẹhin mi, ki ẹ si
mã kiyesi awọn ti nrìn bẹ̃, gẹgẹ bi awa ti
jasi apẹrẹ fun nyin.
18 (Nitori ọ̀pọlọpọ ni nrìn, nipasẹ awọn
ẹniti mo ti nwi fun nyin nigbakugba, ani,
ti mo si nsọkun bi mo ti nwi fun nyin ni-
sisiyi, pe, ọtá agbelebu Kristi ni nwọn :
19 Igbẹhin ẹniti iṣe iparun, ikùn ẹniti
iṣe Ọlọrun wọn, ati ogo ẹniti o wà ninu
itiju wọn, awọn ẹniti ntọju ohun aiye.)
20 Nitori ọlọ̀tọ-ẹgbẹ wa mbẹ li ọrun :
nibiti awa pẹlu gbé nwò ọ̀na fun Olugbala,
Jesu Kristi Oluwa :
21 Ẹniti yio pa ara òṣi wa dà, ki o le ri
gẹgẹ bi ara on tikararẹ̀ ti o li ogo, gẹgẹ bi
iṣẹ agbara nipasẹ eyiti on le fi ṣẹgun ohun
gbogbo fun ara rẹ̀.

Digitized by Google

## ORI 4.

NITORINA, ẹnyin ará mi olufẹ ọ̀wọn ti a
nṣafẹri gidigidi, ayọ̀ ati ade mi, ẹ
duro ṣinṣin ninu Oluwa, ẹnyin olufẹ mi
ọ̀wọn.
2 Emi mbẹ̀ Euodia, mo si mbẹ̀ Sintike,
ki nwọn ki o wà ni inu kanna ninu Oluwa.
3 Mo si mbẹ̀ ọ pẹlu, bi olubaṣiṣẹ mi
olõtọ, ràn awọn obirin wọnni lọwọ ti mba
mi ṣiṣẹ pọ̀ ninu ihin-rere, ati Klementi
pẹlu, ati awọn olubaṣiṣẹ mi miran pẹlu, orukọ
awọn ẹniti mbẹ ninu iwe ìye.
4 Ẹ mã yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo:
mo si tún wi pe, Ẹ mã yọ̀.
5 Ẹ jẹ ki ìwa pẹlẹ nyin di mimọ̀ fun
gbogbo enia. Oluwa kù si dẹ̀dẹ.
6 Ẹ máṣe aniyàn ohunkohun; ṣugbọn
nipa adura ati ẹ̀bẹ pẹlu idupẹ, ẹ mã fi ìbere
nyin hàn fun Ọlọrun li ohun gbogbo.
7 Ati alafia Ọlọrun, ti o jù ìmọran gbo-
gbo lọ, yio pa nyin li àiya ati ọkàn mọ́
ninu Kristi Jesu.
8 Li akotan, ará, ohunkohun ti iṣe otitọ,
ohunkohun ti iṣe ọ̀wọ, ohunkohun ti iṣe
ododo, ohunkohun ti iṣe mimọ́, ohunkohun
ti iṣe fifẹ, ohunkohun ti o ni ihin rere; bi
ìwakiwa kan ba wà, bi iyìnkiyìn kan ba si
wà, ẹ mã gbà nkan wọnyi rò.
9 Nkan wọnni, ti ẹnyin ti kọ́, ti ẹnyin si
ti gbà, ti ẹnyin si ti gbọ́, ti ẹnyin si ti ri
lọwọ mi, ẹ mã ṣe wọn: Ọlọrun alafia yio
si mã wà pẹlu nyin.
10 Ṣugbọn emi yọ̀ gidigidi ninu Oluwa,
pe nisisiyi ãjò nyin nitori mi tún di pipọ;
nipasẹ eyiti ẹnyin ti ṣe ãjò, ṣugbọn ẹnyin
kò ni akokò.
11 Kì iṣe pe emi nwi nitori aini: ni-
toripe ipòkipo ti mo ba wà, mo ti kọ́ lati
mã wà ni itẹlọrùn.
12 Mo mọ̀ bi ãti iṣe di rirẹ̀-silẹ, mo si
mọ̀ bi ãti iṣe di pipọ̀: ni ibi gbogbo ati li
ohun gbogbo li a ti nkọ́ mi lati mã jẹ ajẹyó
ati lati wà li aijẹ, lati mã ni anijù ati lati
ṣe alaini.
13 Emi le ṣe ohun gbogbo ninu Kristi
ẹniti nfi agbara fun mi.
14 Ṣugbọn ẹnyin si ṣeun gidigidi niti
ẹnyin nṣe alabapin ninu ipọnju mi.
15 Njẹ ki ẹnyin ará Filippi ki o mọ̀ pẹlu
pe, li àteteko bẹrẹ ihin-rere, nigbati mo ti
Makedonia lọ kuro, ko si Ijọ kan ti o ba
mi ṣe alabapin nipa gbigbà ati fifunni, bi-
koṣe ẹnyin nikanṣoṣo.
16 Nitori ẹnyin ranṣẹ si mi ni Tessa-
lonika lẹ̃kan nitõtọ, ati lẹ̃keji ẹ̀wẹ nitori
aini mi.
17 Kì iṣe nitori ti emi nfẹ ẹ̀bun: ṣu-
gbọn emi nfẹ eso ti yio mã di pipọ nitori
nyin.
18 Ṣugbọn mo ti gbà gbogbo wọn, mo si
ti di pipọ: mo si kún, mo si ti gbà nkan
wọnni ti a ti rán lati ọdọ nyin wá lọwọ
Epafroditu, ọrẹ olõrùn didùn, ẹbọ itẹwọgbà,
ti iṣe inudidùn gidigidi si Ọlọrun.
19 Ṣugbọn Ọlọrun mi yio pèse fun gbo-
gbo aini nyin, gẹgẹ bi ọ̀pọ̀lọpọ ọrọ̀ rẹ̀ ninu
ogo ninu Kristi Jesu.
20 Ṣugbọn ogo ni fun Ọlọrun ati Baba
wa lai ati lailai. Amin.
21 Ẹ kí olukuluku enia mimọ́ ninu
Kristi Jesu. Awọn arakọnrin ti o wà pẹlu
mi kí nyin.
22 Gbogbo awọn enia mimọ́ kí nyin,
pẹlupẹlu awọn ti iṣe ti ará ile Kesari.
23 Ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ki o
wà pẹlu gbogbo nyin. Amin.

---

A kọ ọ si awọn ara Filippi lati Romu
lọ lati ọwọ́ Epafroditu.

Digitized by Google

EPISTELI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA KOLOSSE.

## ORI 1.

PAULU, Aposteli Jesu Kristi nipa ifẹ
Ọlọrun, ati Timoteu arakọnrin wa,
2 Si awọn enia mimọ ati awọn olododo
ará ninu Kristi ti o wà ni Kolosse: Ore-ọfẹ
fun nyin, ati alafia, lati ọdọ Ọlọrun Baba
wa, ati Jesu Kristi Oluwa wá.
3 Awa ndupẹ lọwọ Ọlọrun ati Baba
Jesu Kristi Oluwa wa, awa si ngbadura fun
nyin nigbagbogbo,
4 Nigbati awa gburó igbagbọ nyin ninu
Kristi Jesu, ati ifẹ ti ẹnyin ni si gbogbo
awọn enia mimọ.
5 Nitori ireti ti a gbé leke fun nyin li
ọrun, nipa eyiti ẹnyin ti gbọ ṣaju ninu ọrọ
otitọ ihin-rere;
6 Eyiti o tọ nyin wá, bi o si ti ri ni gbo-
gbo aiye; ti o si nso eso jade, bi o si ti nṣe
ninu nyin pẹlu, lati ọjọ ti ẹnyin ti gbọ ọ, ti
ẹnyin si ti mọ ore-ọfẹ Ọlọrun li otitọ:
7 Gẹgẹ bi ẹnyin si ti kọ lati ọwọ Epafra
iranṣẹ ẹlẹgbẹ wa olufẹ, ẹniti iṣe olododo
iranṣẹ Kristi fun nyin;
8 Ẹniti o si ti ròhin ifẹ nyin ninu Ẹmí
fun wa pẹlu.
9 Awa pẹlu nitori eyi, lati ijọ ti a ti
gbúro rẹ, awa kò si simi lati mã gbadura
fun nyin, ati lati ma bẹbẹ pe ki ẹnyin ki o
le kún fun ìmọ ifẹ rẹ ninu ọgbọn ati imoye
gbogbo ti iṣe ti Ẹmí;
10 Ki ẹ le mã rìn ni yiyẹ niti Oluwa si
ìwu gbogbo, ki ẹ le jẹ eleso ninu iṣẹ rere
gbogbo, ki ẹ si le mã di pipọ ninu ìmọ
Ọlọrun;
11 Ki a le fi ipá gbogbo mu nyin li ọkàn
le, gẹgẹ bi agbara rẹ ti o li ogo, sinu sũru
ati ipamọra gbogbo pẹlu ayọ;
12 Awa ndupẹ lọwọ Baba, ẹniti o ti mu
wa di alabapin ninu ilẹnini awọn enia
mimọ ninu imọlẹ:
13 Ẹniti o ti gbà wa kuro lọwọ agbara
òkunkun, ti o si ti yi wa pada sinu ijọba
ayanfẹ ọmọ rẹ:
14 Ninu ẹniti awa gbé ti ni idande nipa
ẹjẹ rẹ, ani idariji ẹṣẹ:
15 Ẹniti iṣe aworan Ọlọrun ti a kò ri,
ati akọbi ninu gbogbo ẹda:
16 Nitori nipasẹ rẹ li a ti dá ohun gbo-
gbo, awọn ti mbẹ li ọrun, ati awọn ti mbẹ
li aiye, ati eyiti a ri, ati eyiti a ṣe alairi,
nwọn iba ṣe itẹ, tabi awọn ijọba, tabi awọn
ijoye, tabi awọn alagbara: nipasẹ rẹ li a ti
dá ohun gbogbo, ati fun u:
17 On si wà ṣaju ohun gbogbo, ati ni-
pasẹ rẹ li a si mu ohun gbogbo duro.
18 On si jẹ ori fun ara na, ani ijọ: ẹniti
iṣe ipilẹṣẹ, akọbi lati inu okú wá; pe ki on
ki o le ni ipò giga julọ ninu ohun gbogbo.
19 Nitoripe ifẹ Baba ni pe, ninu rẹ ni
ẹkún gbogbo yio ma gbé;
20 O si ti fi ẹjẹ agbelebu rẹ nṣe alafia
nipasẹ rẹ lati ṣe ìlaja ohun gbogbo si on
tikararẹ; mo ni, nipasẹ rẹ, nwọn iba ṣe
ohun ti mbẹ li aiye, tabi ohun ti mbẹ li
ọrun.
21 Ati ẹnyin, ẹniti a ti sọdi alejò ati
ọtá lakokò kan ri li àiya nyin nipa iṣẹ bu-
buru, ẹnyin li o si ti ṣe ìlaja fun nisisiyi,
22 Ninu ara rẹ nipa ikú, lati mu nyin
wá ni mimọ ati ailabawọn ati ainibawi
niwaju rẹ:
23 Bi ẹnyin ba duro nipa igbagbọ ni
ifẹsẹ-mulẹ ati iduro gangan, ti a kò si mu
nyin yẹsẹ kuro ninu ireti ihin-rere, ti ẹn-
yin ti gbọ, eyiti a si ti wasu fun gbogbo
ẹda ti mbẹ labẹ ọrun; nipasẹ eyiti a fi emi
Paulu ṣe iranṣẹ;
24 Emi ẹniti nyọ nisisiyi nitori ìya mi
fun nyin, ẹniti nmu ipọnju Kristi ti o kù
lẹhin kún li ara mi, nitori ara rẹ, ti iṣe ijọ
enia Ọlọrun:
25 Nipa eyiti a fi mi ṣe iranṣẹ, gẹgẹ bi
ipinfunni Ọlọrun ti a fifun mi nitori nyin,
lati mu ọrọ Ọlọrun ṣe nipa iwasu;
26 Ani ohun ijinlẹ na ti a ti fi pamọ lati
igba aiyeraiye ati lati irandiran gbogbo,

Digitized by Google

ṣugbọn ti a nfihàn nisisiyi fun awọn enia mimọ́:
27 Ẹniti Ọlọrun nfẹ fi ọrọ̀ ogo ohun ijinlẹ na yi hàn fun larin awọn Keferi; ti iṣe Kristi ninu nyin, ireti ogo:
28 Ẹniti awa nwasu, ti a nkìlọ fun olukuluku enia, ti a si nkọ́ olukuluku enia ninu ọgbọ́n gbogbo; ki a le mu olukuluku enia wá ni ìwa pipé ninu Kristi Jesu:
29 Nipasẹ eyiti emi nṣe lãlã pẹlu, ti mo si nlàkaka gẹgẹ bi iṣẹ agbara rẹ̀, ti nfi agbara ṣiṣẹ gidigidi ninu mi.

## ORI 2.

NITORI emi nfẹ ki ẹnyin ki o le mọ̀ bi iwaya-ìja na ti mo ni fun nyin ti pọ̀ to, ati fun awọn ará Laodikea, ati fun iye awọn ti kò ti iri oju mi nipa ti ara;
2 Ki nwọn ki-o le ni itunu li àiya wọn, ẹniti a ti dàpọ ṣọkan ninu ifẹ, ati si gbogbo ẹkún ọrọ̀ imoye dajudaju, si jijẹwọ ohun ijinlẹ Ọlọrun, ati ti Baba, ati ti Kristi;
3 Ninu ẹniti a ti fi gbogbo iṣura ọgbọ́n ati ti ìmọ pamọ́ si.
4 Eyi ni mo si nwi, ki ẹnikẹni ki o máṣe fi ọ̀rọ ẹ̀tan tàn nyin jẹ.
5 Nitoripe bi emi kò tilẹ si lọdọ nyin nipa ti ara, ṣugbọn mo wà pẹlu nyin nipa ti ẹmí, emi nyọ̀ emi si nwò ìrin titọ nyin, ati iduroṣinṣin igbagbọ́ nyin ninu Kristi.
6 Nitorina bi ẹnyin ti gbà Kristi Jesu Oluwa, bẽni ki ẹ ma rìn ninu rẹ̀:
7 Ki a fi ẹsẹ nyin mulẹ, ki a si gbé nyin ró ninu rẹ̀, ki a si mu nyin li ọkàn le ninu igbagbọ́, gẹgẹ bi a ti kọ́ nyin, ki ẹ si mã pọ̀ ninu ikanna pẹlu idupẹ.
8 Ẹ mã kiyesara ki ẹnikẹni ki o máṣe bà nyin jẹ nipa ìmọ ati ẹ̀tan asan, nipa ipitan enia, nipa ipilẹṣẹ araiye, ti kò ṣe ti Kristi.
9 Nitoripe ninu rẹ̀ ni gbogbo ẹkún Iwa-Ọlọrun ngbé li ara-iyara.
10 A si ti ṣe nyin li aṣepé ninu rẹ̀, ẹniti iṣe ori fun gbogbo ijoye ati alagbara:
11 Ninu ẹniti a si nfi ikọla aifọwọṣe kọ nyin nilà, nipa eyiti ẹnyin pẹlu ti bọ ara ẹ̀ṣẹ ẹran-ara silẹ, nipa ikọla ti Kristi:
12 Bi a ti sin nyin pọ̀ pẹlu rẹ̀ nipa baptismu, nipasẹ eyiti a si ti jí nyin dide pẹlu rẹ̀ nipa igbagbọ́ ti iṣe iṣẹ Ọlọrun, ẹniti o ti jí i dide kuro ninu okú.
13 Ati ẹnyin, ẹniti o ti kú ninu ẹ̀ṣẹ nyin ati aikọla ara nyin, li o si ti sọdi alãye pọ̀ pẹlu rẹ̀, o si ti dari gbogbo ẹ̀ṣẹ nyin jì nyin;
14 O si ti nù iwe idasilẹ ti a fi ọwọ́ kọ nì kuro ti o lodi si wa, eyiti o si ti lodi si wa, o si ti mu u kuro loju ọ̀na, o si kàn a mọ agbelebu;
15 O si ti bà awọn ijoye ati awọn alagbara jẹ, o si ti fi wọn hàn ni gbangba, o nṣẹgun wọn ninu on tikararẹ̀.
16 Nitorina ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o mã ṣe idajọ nyin nitori jijẹ, tabi mimu, tabi ibọwọ fun ọjọ mimọ́, tabi oṣù titun, tabi ọjọ isimi:
17 Awọn ti iṣe ojiji ohun ti mbọ̀; ṣugbọn ti Kristi ni ara iṣe.
18 Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o pè nyin lẹjọ niti ère nyin, ti iṣe adabọwọ irẹlẹ, ati itẹriba sisìn awọn angeli, niti yiyọju sinu nkan wọnni ti on kò ri, ti o nti ipa ara rẹ̀ ṣeféfe asan.
19 Ti nwọn kò si di Ori nì mu ṣinṣin, lati inu eyiti gbogbo ara nipa orike ati ìde ti nri bíbọ gbà, ti a si so gbogbo rẹ̀ pọ̀, ti o si npọ̀ si i nipa ibisi Ọlọrun.
20 Nitorina bi ẹnyin ba ti kú pẹlu Kristi kuro ninu ipilẹṣẹ aiye, ẽhatiṣe, bi ẹnipe ẹnyin nrìn nipa ti aiye, ti ẹnyin ntẹriba fun idasilẹ enia,
21 (Má fi ara kàn; má fi ẹnu kàn; má fi ọwọ́ kàn;
22 Gbogbo eyiti yio parun nipa ìlo;) gẹgẹ bi ofin ati ẹkọ́ enia?
23 Awọn nkan ti o ni ifihàn ọgbọ́n nitõtọ, nipa ìsin ifẹ inu ẹni, ati irẹlẹ, ati li aida ara si; li aijasi ọlá kan fun itẹlọrùn ara.

## ORI 3.

NJẸ bi ẹnyin ba ti jinde pẹlu Kristi, ẹ mã ṣafẹri ohun ti mbẹ loke, nibiti Kristi gbé joko li ọwọ́ ọtun Ọlọrun.
2 Ẹ mã gbé ifẹ ọkàn nyin soke si ohun ti mbẹ li ọrun, ki iṣe si ohun ti mbẹ li aiye.
3 Nitori ẹnyin ti kú, a si fi ìye nyin pamọ́ pẹlu Kristi ninu Ọlọrun.
4 Nigbati Kristi, ẹniti iṣe ìye wa yio fi ara hàn, nigbana li ẹnyin pẹlu o fi ara hàn pẹlu rẹ̀ ninu ogo.
5 Nitorina ẹ mã pọ́n ẹ̀ya ara nyin ti mbẹ li aiye loju; àgbere, ìwa-ẽri, ifẹkufẹ, ifẹ buburu, ati ojukòkoro, ti iṣe ibọriṣa:
6 Nitori ohun ti ibinu Ọlọrun fi mbọ̀wa sori awọn ọmọ alaigbọran.
7 Ninu eyiti, ẹnyin pẹlu ti nrìn nigba kan ri, nigbati ẹnyin ti wà ninu wọn.
8 Ṣugbọn nisisiyi ẹ fi gbogbo wọnyi silẹ pẹlu; ibinu, irunu, arankàn, ọ̀rọ-òdi si Ọlọrun, ati ọ̀rọ ẽri kuro li ẹnu nyin.
9 Ẹ má si ṣe purọ́ fun ọmọnikeji nyin, kiyesi i pe ẹnyin ti bọ́ ogbologbo ọkọnrin nì silẹ pẹlu iṣe rẹ̀;

Digitized by Google

10 Ẹsi ti gbé ọkọnrin titun nì wọ̀, eyiti a sọ-
di titun nipa ìmọ gẹgẹ bi aworan ẹniti o da a:
11 Nibiti kò si Hellene tabi Ju, ikọla
tabi alaikọla, alaigbede, ara Skitia, ẹrú
tabi omnira: ṣugbọn Kristi li ohun gbo-
gbo, ati ninu ohun gbogbo.
12 Nitorina, bi ayanfẹ Ọlọrun, ẹni mimọ́
ati olufẹ, ẹ gbé iyọnu ãnu wọ̀, iṣeun, irẹlẹ
ọkàn, inu tutù, ipamọra;
13 Ẹ mã fi sũru gbà ọmọnikeji nyin, ki
ẹ si ma darijì ọmọnikeji nyin, bi ẹnikẹni
ba ni ìja si ẹnikan: bi Kristi ti darijì nyin,
gẹgẹ bẹ̃ni ki ẹnyin ki o mã ṣe pẹlu.
14 Ati bori gbogbo nkan wọnyi, ẹ gbé
ifẹ wọ̀, ti iṣe àmure ìwa pipé.
15 Ẹ si jẹ ki alafia Ọlọrun ki o mã ṣe
akoso àiya nyin, sinu eyiti a pè nyin pẹlu
ninu ara kan; ki ẹ si ma dupẹ.
16 Ẹ jẹ ki ọ̀rọ Kristi ki o mã gbé inu
nyin li ọ̀pọlọpọ ninu ọgbọ́n gbogbo; ki ẹ
ma kọ́, ki ẹ si ma gbà ara nyin niyanju
ninu orin mimọ́, ati orin iyìn, ati orin ẹmí,
ẹ mã fi ore-ọfẹ kọrin li àiya nyin si Oluwa.
17 Ohunkohun ti ẹnyin ba si nṣe li ọ̀rọ
tabi ni iṣe, ẹ mã ṣe gbogbo wọn li orukọ
Jesu Oluwa, ẹ mã fi ọpẹ́ fun Ọlọrun ati
Baba nipasẹ rẹ̀.
18 Ẹnyin aya, ẹ mã foribalẹ fun awọn
ọkọ nyin, gẹgẹ bi o ti yẹ si ninu Oluwa.
19 Ẹnyin ọkọ, ẹ fẹ awọn aya nyin, ẹ má
si ṣe korò si wọn.
20 Ẹnyin ọmọ, ẹ mã tẹriba fun awọn õbi
nyin li ohun gbogbo: nitori eyi bayi dara
gidigidi lọdọ Oluwa.
21 Ẹnyin baba, ẹ máṣe mu awọn ọmọ
nyin binu, ki inu wọn ki o máṣe bajẹ.
22 Ẹnyin ẹrú, ẹ foribalẹ fun awọn oluwa
nyin nipa ti ara li ohun gbogbo; kì iṣe ti
arojuṣe, bi awọn alaṣewù enia; ṣugbọn niti
inu kanṣoṣo ni bibẹ̀ru Ọlọrun:
23 Ohunkohun ti ẹnyin ba nṣe, ẹ mã fi
tọkàntọkan ṣe e, gẹgẹ bi fun Oluwa, kì si
iṣe fun enia;
24 Ki ẹ mọ̀ pe lọwọ Oluwa li ẹnyin o
gbà ère ilẹnini kan: nitori ẹnyin nsìn
Kristi Oluwa.
25 Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba ṣe ohun aiṣo-
dodo, yio si gbà nitori aiṣododo na ti o ti
ṣe: kò si si ojusaju enia.

ORI 4.

ẸNYIN oluwa, ẹ ma fi eyiti o tọ́, ti o si
dọgba fun awọn ẹrú nyin; ki ẹ si mọ̀
pe ẹnyin pẹlu ni Oluwa kan li ọrun.
2 Ẹ mã duro ninu adura igbà, ki ẹ si mã
ṣọra ninu ọkanna pẹlu idupẹ;
3 Pẹlupẹlu ẹ mã gbadura fun wa, ki
Ọlọrun ki o le ṣí ilẹkun ọ̀rọ silẹ fun wa,
lati mã sọ ohun ijinlẹ Kristi, nitori eyiti
mo ṣe wà ninu ìde pẹlu:
4 Ki emi ki o le fi i hàn, gẹgẹ bi o ti tọ́
fun mi lati mã sọ.
5 Ẹ mã rìn nipa ọgbọ́n si awọn ti mbẹ
lode, ki ẹ si ma ṣe ìrapada akokò.
6 Ẹ jẹ ki ọ̀rọ nyin ki o ma dàpọ mọ́ ore-
ọfẹ nigbagbogbo, eyiti a fi iyọ̀ dùn, ki
ẹnyin ki o le mọ̀ bi ẹnyin o ti ma dá oluku-
luku enia lohùn.
7 Gbogbo ijoko mi ni Tikiku yio sọ fun
nyin, ẹniti iṣe arakọnrin olufẹ, ati iranṣẹ
olododo, ati ọmọ-ọdọ ẹgbẹ ninu Oluwa:
8 Ẹniti mo ti rán si nyin nitori eyi
kanna, ki on ki o le mọ̀ ijoko nyin, ki o si
le tù nyin li àiya;
9 Pẹlu Onesimu, arakọnrin olododo ati
olufẹ, ẹniti iṣe ọkan ninu nyin. Awọn ni
yio sọ ohun gbogbo ti a nṣe nihinyi fun
nyin.
10 Aristarku, ẹgbẹ mi ninu tubu kí
nyin, ati Marku, ọmọ arabirin Barnaba,
(nipasẹ ẹniti ẹnyin ti gbà aṣẹ: bi o ba si
wá sọdọ nyin, ẹ gbà a;)
11 Ati Jesu, ẹniti a npè ni Justu, ẹniti
iṣe ti awọn onila. Kìki awọn wọnyi ni
olubaṣiṣẹ mi fun ijọba Ọlọrun, awọn ẹniti
o ti jasi itunu fun mi.
12 Epafra, ẹniti iṣe ọkan ninu nyin,
iranṣẹ Kristi, kí nyin, on ṣiṣẹ nigbagbogbo
fun nyin nipa adura gbigbona pe, ki ẹnyin
ki o le wà ni pipé ati ni kíkun ninu gbo-
gbo ifẹ Ọlọrun.
13 Nitori mo jẹri rẹ̀ pe, o ni itara nla
fun nyin, ati fun awọn ti o wà ni Laodi-
kea, ati awọn ti o wà ni Hierapoli.
14 Luku, oniṣegun olufẹ, ati Dema kí
nyin.
15 Ẹ kí awọn ará ti o wà ni Laodikea,
ati Nimfa, ati ijọ ti o wà ni ile rẹ̀.
16 Nigbati a ba si kà iwe yi larin nyin
tan, ki ẹ mu ki a kà a pẹlu ninu ijọ Lao-
dikea; bẹ̃ gẹgẹ ni ki ẹnyin ki o kà iwe ti
o ti Laodikea wá.
17 Ki ẹ si wi fun Arkippu pe, Kiyesi
iṣẹ iranṣẹ ti iwọ ti gbà nipa ti Oluwa, ki
iwọ ki o mu u ṣẹ.
18 Ikíni nipa ọwọ́ emi Paulu. Ẹ mã
ranti ìde mi. Ki ore-ọfẹ ki o wà pẹlu
nyin. Amin.

A kọ ọ lati Romu lọ si awọn ara
Kolosse lati ọwọ́ Tikiku ati
Onesimu.

Digitized by Google

EPISTELI IKINI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA TESSALONIKA.

ORI 1.

PAULU, ati Silfanu, ati Timoteu, si ijọ
Tessalonika, ti o wà ninu Ọlọrun
Baba, ati ninu Jesu Kristi Oluwa: Ore-ọfẹ
si nyin, ati alafia, lati ọdọ Ọlọrun Baba
wa, ati Jesu Kristi Oluwa wá.
2 Awa ndupẹ lọwọ Ọlọrun nigbagbogbo
fun gbogbo nyin, awa nṣe iranti nyin ninu
adura wa;
3 Awa nranti iṣẹ igbagbọ́ nyin, ati iṣẹ
ifẹ nyin li aisimi, ati sũru nyin ni ireti
Jesu Kristi Oluwa wa, niwaju Ọlọrun ati
Baba wa;
4 Awa mọ̀, ara olufẹ, yiyàn nyin.
5 Nitori ihin-rere wa kò wá sọdọ nyin li
ọ̀rọ nikan, ṣugbọn li agbara pẹlu, ati nipa
Ẹmí Mimọ́, ati ni igbẹkẹle ọ̀pọlọpọ; bi
ẹnyin ti mọ̀ irú enia ti awa jẹ́ larin nyin
nitori nyin.
6 Ẹnyin si di ọmọ lẹhin wa, ati ti Olu-
wa, ẹnyin si ti gbà ọ̀rọ na ninu ipọnju
ọ̀pọlọpọ, pẹlu ayọ̀ Ẹmí Mimọ́:
7 Bẹ̃li ẹnyin si jasi apẹrẹ fun gbogbo
awọn ti o gbagbọ́ ni Makedonia ati Akaia.
8 Nitoripe lati ọdọ nyin lọ li ọ̀rọ Oluwa
ti dún jade, kì iṣe ni kìki Makedonia ati
Akaia nikan, ṣugbọn pẹlupẹlu ni ibi gbo-
gbo ni ìhin igbagbọ́ nyin si Ọlọrun tàn
kalẹ; tobẹ̃ ti awa kò ni isọ̀rọ ohunkohun mọ́.
9 Nitoripe awọn tikara wọn ròhin nipa
ti wa, irú iwọle ti awa ti ni si nyin, bi
ẹnyin si ti yipada si Ọlọrun kuro ninu ere
lati mã sìn Ọlọrun alãye ati otitọ;
10 Ati lati duro dè Ọmọ rẹ̀ lati ọrun wá,
ẹniti o si jinde kuro ninu okú, ani Jesu
na, ẹniti ngbà wa kuro ninu ibinu ti mbọ̀.

ORI 2.

NITORI ẹnyin tikara nyin mọ̀, ará, irú
iwọle wa si nyin pe kì iṣe lasan:
2 Ṣugbọn pẹlupẹlu lẹhin igbati awa ti
jìya ṣaju, ti a si fi itiju jẹ wa nìya ni Fi-
lippi, gẹgẹ bi ẹnyin ti mọ̀, awa ni igboiya
ninu Ọlọrun wa lati sọ̀rọ ihin-rere Ọlọrun
fun nyin pẹlu ọ̀pọlọpọ iwaya-ìja.
3 Nitoripe ọ̀rọ igbiyanju wa kì iṣe ti
ẹ̀tan, tabi ti ìwa-ẽri, tabi ti arekereke:
4 Ṣugbọn bi a ti fifun wa lati ọdọ Ọlọrun
wá lati fi wa ṣe iriju olododo ti ihin-rere,
bẹ̃ gẹgẹ li awa si nsọ nitõtọ; kì iṣe bi ẹniti
nwù enia, bikoṣe Ọlọrun, ti ndan àiya wa
wò.
5 Nitori kì iṣe li akokò kan li awa nlò
ọ̀rọ ẹ̀tan, gẹgẹ bi ẹnyin ti mọ̀, tabi ṣiṣe
iboju ojukòkoro; Ọlọrun sá li ẹlẹri wa:
6 Tabi lọdọ enia li awa nwá ogo, bẹ̃ni
kì iṣe lọdọ nyin, tabi lọdọ ẹlomiran, ni-
gbati awa iba lò agbara lori nyin bi awọn
aposteli Kristi.
7 Ṣugbọn awa ṣe pẹlẹ lọdọ nyin, gẹgẹ bi
oluṣọ ọmọ ntọju awọn ọmọ rẹ̀:
8 Bẹ̃ gẹgẹ li awa si nṣe ifẹ inu-rere si
nyin, awa si nfẹ lati fifun nyin, kì iṣe ihin-
rere Ọlọrun nikan, ṣugbọn ẹmí awa tikara
wa pẹlu, nitoriti ẹnyin jẹ ẹni ọ̀wọ́n fun wa.
9 Nitori ẹnyin ranti, ará, ìṣẹ́ ati lãlã
wa: nitori awa nṣe lãlã li ọsán ati li oru,
nitoriti awa kò fẹ ná ẹnikẹni li owo ninu
nyin, awa si ti wasu ihin-rere Ọlọrun fun
nyin.
10 Ẹnyin si li ẹlẹri, ati Ọlọrun pẹlu, bi
awa tikara wa ti jẹ mimọ́, ati olododo, ati
alailẹgan larin ẹnyin ti o gbagbọ́:
11 Gẹgẹ bi ẹnyin si ti mọ̀ bi awa ti gbà
olukuluku enia niyanju ninu nyin, ti a si
tù nyin ninu, ti a si kìlọ fun nyin, gẹgẹ bi
baba ti iṣe si awọn ọmọ rẹ̀,
12 Ki ẹnyin ki o le mã rìn ni yiyẹ niti
Ọlọrun, ẹniti o ti pè nyin sinu ijọba ati
ogo rẹ̀.
13 Nitori eyi na pẹlu li awa ṣe ndupẹ
lọwọ Ọlọrun li aisimi, nitoripe, nigbati
ẹnyin gbà ọ̀rọ Ọlọrun, eyi ti ẹnyin gbọ́ li
ẹnu wa, ẹnyin kò gbà a bi ẹnipe ọ̀rọ enia,
ṣugbọn bi o ti jasi nitõtọ, ọ̀rọ Ọlọrun,
eyiti o ṣiṣẹ gidigidi ninu ẹnyin ti o gbagbọ́
pẹlu.

Digitized by Google

14 Nitoripe, ará, ẹnyin di ọmọ lẹhin ijọ enia Ọlọrun ti o wà ni Judea, awọn ti o wà ninu Kristi Jesu: nitoripe ẹnyin pẹlu jìya iru ohun kanna lọwọ awọn ara ilu nyin, gẹgẹ bi awọn pẹlu ti jìya lọwọ awọn Ju:
15 Awọn ẹniti o pa Jesu Oluwa, ati awọn woli awọn tikarawọn, nwọn si fi inunibini tì wa jade; nwọn kò si ṣe ifẹ Ọlọrun, nwọn si wà lodi si gbogbo enia:
16 Nwọn kọ̀ fun wa lati sọrọ fun awọn Keferi ki nwọn ki o le là, lati kún ẹ̀ṣẹ wọn nigbagbogbo: nitorina ibinu si bọ̀wa sori wọn titi de opin.
17 Ṣugbọn awa, ará, ẹniti a ti gbà kuro lọdọ nyin ni igba kukuru kan li oju, kì iṣe li àiya wa, awa nfi ifẹ nla ṣe aniyan jù gidigidi lati ri oju nyin.
18 Nitorina awa nfẹ lati tọ̀ nyin wá, ani emi Paulu, lẹrinkan ati nigba keji; ṣugbọn Satani dè wa li ọ̀na.
19 Nitoripe kini ireti wa, tabi ayọ̀ wa, tabi ade ogo wa? Nitõtọ kò ṣe ẹnyin ni niwaju Jesu Kristi Oluwa wa ni àbọ rẹ̀?
20 Nitori ẹnyin ni ogo ati ayọ̀ wa.

## ORI 3.

NITORINA nigbati awa kò si le gbiyanju pẹ mọ́, awa rò pe o dara fun wa lati jọwọ awa nikan si Ateni;
2 Awa si rán Timoteu, arakọnrin wa, ati iranṣẹ Ọlọrun, ati olubaṣiṣẹ wa ninu ihin-rere Kristi, lati fi ẹsẹ nyin mulẹ, ati lati tù nyin ninu ninu igbagbọ́ nyin:
3 Ki a máṣe fi ẹ̀tan mu ẹnikẹni yẹsẹ nipa wahalà wọnyi: nitori ẹnyin tikara nyin mọ̀ pe a ti yàn wa sinu rẹ̀.
4 Nitoripe nigbati awa wà lọdọ nyin, awa ti sọ fun nyin ṣaju nitõtọ pe, awa o ri wahalà; gẹgẹ bi o si ti ṣẹ, ti ẹnyin si mọ̀.
5 Nitori idi eyi, nigbati emi kò le duro pẹ mọ́, mo si ranṣẹ, lati mọ̀ igbagbọ́ nyin, bi o le ṣe ki oludanwò nì ki o máṣe dán nyin wò, lãlã wa a si jasi asan.
6 Ṣugbọn nisisiyi nigbati Timoteu si ti ti ọdọ nyin wá sọdọ wa, ti o si ti mu ihin rere igbagbọ́ ati ifẹni nyin wá fun wa, ati pe ẹnyin ni iranti rere fun wa nigbagbogbo, ẹnyin si nfẹ gidigidi lati ri wa, bi awa pẹlu si ti nfẹ lati ri nyin:
7 Nitorina, ará, awa ni itunu lori nyin ninu gbogbo wahalà ati ipọnju wa nipa igbagbọ́ nyin:
8 Nitori awa yè nisisiyi, bi ẹnyin ba duroṣinṣin ninu Oluwa.
9 Nitori ọpẹ́ kili awa le tún ma dá lọwọ Ọlọrun nitori nyin, nitori gbogbo ayọ̀ nipasẹ eyiti awa nyọ̀ niwaju Ọlọrun wa nitori nyin;
10 Li ọsán ati li oru awa ngbadura gidigidi pe, ki awa ki o le ri oju nyin, ki awa ki o le ṣe aṣepé eyiti o kù ninu igbagbọ́ nyin?
11 Njẹ ki Ọlọrun tikararẹ̀, ati Baba wa, ati Jesu Kristi Oluwa wa, ki o ṣe amọ̀na wa sọdọ nyin.
12 Ki Oluwa ki o si mã mu nyin bisi i, ki ẹ si mã pọ̀ ninu ifẹ si ọmọnikeji nyin, ati si gbogbo enia, gẹgẹ bi awa ti nṣe si nyin:
13 Nikẹhin ki o le fi àiya nyin balẹ li ailabuku ninu ìwa mimọ́ niwaju Ọlọrun, ani Baba wa, nigba atiwá Jesu Kristi Oluwa wa pẹlu gbogbo awọn enia mimọ́ rẹ̀.

## ORI 4.

PẸLUPẸLU awa sì mbẹ̀ nyin, ará, awa si ngbà nyin niyanju ninu Jesu Oluwa, pe bi ẹnyin ti tẹwọgbà lọwọ wa bi ẹnyin iba ti mã rìn, ti ẹnyin iba si mã wù Ọlọrun, ani bi ẹnyin ti nrìn, ki ẹnyin le mã pọ̀ si i gidigidi lọpọlọpọ.
2 Nitori ẹnyin mọ̀ irú ofin ti a ti fifun nyin nipa Jesu Oluwa.
3 Nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, ani ìwa mimọ́ nyin, pe ki ẹnyin ki o takéte si àgbere:
4 Ki olukuluku nyin ki o le mọ̀ bi on iba ti ma lò èlo rẹ̀ ni ìwa mimọ́ ati ni ti ọlá;
5 Kì iṣe ni ṣiṣe ifẹkufẹ, gẹgẹ bi awọn Keferi ti kò mọ̀ Ọlọrun:
6 Ki ẹnikẹni ki o máṣe rekọja, ki o má si ṣe rẹ́ arakọnrin rẹ̀ jẹ li ohunkohun: nitoripe Oluwa ni iṣe olugbẹsan gbogbo irú enia bẹ̃, gẹgẹ bi awa si ti sọ fun nyin niṣaju, ti a si jẹri pẹlu.
7 Nitoripe Ọlọrun kò pè wa si ìwa-ẽri, bikoṣe si ìwa-mimọ́.
8 Nitorina ẹnikẹni ti o ba nkẹgan, kò kẹgan enia, bikoṣe Ọlọrun, ẹniti o si ti fi Ẹmí Mimọ́ rẹ̀ fun wa pẹlu.
9 Ṣugbọn nipa ti ifẹ awọn ará, ẹnyin kò ni pe, ki emi kọwe si nyin: nitori a ti kọ́ ẹnyin tikara nyin lati ọdọ Ọlọrun wá lati mã fẹ ọmọnikeji nyin.
10 Nitõtọ ẹnyin si nṣe e si gbogbo awọn ará ti o wà ni Makedonia gbogbo: ṣugbọn awa mbẹ̀ nyin, ará, pe ki ẹnyin ki o mã pọ̀ sĩ gidigidi;
11 Ati pe ki ẹnyin ki o mã ṣe aniyan gidigidi lati gbé jẹ, ati lati ma ṣiṣẹ ti ẹnyin tikara nyin, ati lati mã fi ọwọ́ ẹnyin tikara nyin ṣiṣẹ, gẹgẹ bi awa ti paṣẹ fun nyin;
12 Ki ẹnyin ki o le ma rìn ni irin pipé si

Digitized by Google

awọn ti mbẹ lode, ki ẹnyin ki o má si ṣe
alaini ohunkohun.
13 Ṣugbọn emi kò fẹ ki ẹnyin ki o jẹ
òpe, ará, sipa ti awọn ti o sùn, pe ki ẹnyin
ki o máṣe binujẹ, gẹgẹ bi awọn ẹlomiran ti
kò ni ireti.
14 Nitoripe bi awa ba gbagbọ́ pe Jesu kú
o si jinde, gẹgẹ bẽli awọn pẹlu ti o sùn
nipa ti Jesu li Ọlọrun yio mu wá pẹlu rẹ̀.
15 Nitori eyiyi li awa wi fun nyin nipa
ọ̀rọ Oluwa, pe awa ti o wà lãye, ti a si kù
titi di igba wíwa Oluwa, awa kì yio ṣaju
awọn ti o sùn.
16 Nitori Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ lati
ọrun wá ti on ti ariwo, pẹlu ohùn olori
awọn angeli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn
okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde:
17 Nigbana li a o si gbà awa ti o wà
lãye ti o si kù soke pẹlu wọn sinu awọ-
sanma, lati pade Oluwa li oju ọrun: bẽli
awa o si ma wà titi lai pẹlu Oluwa.
18 Nitorina ẹ ma fi ọ̀rọ wọnyi gbà ara
nyin niyanju.

## ORI 5.

ṢUGBỌN niti igba ati akokò wọnni, ará,
ẹnyin kò ni pe, ki emi ki o ma kọwe
si nyin.
2 Nitoripe ẹnyin tikara nyin mọ̀ daju-
daju pe, ọjọ Oluwa mbọ̀wa gẹgẹ bi olè li
oru.
3 Nitori nigbati nwọn o ma wipe, Alafia
ati ailewu; nigbana ni iparun ojijì mbọ̀wa
sori wọn, gẹgẹ bi irọbi lori obirin ti o lóyun;
nwọn kì yio si bọ́.
4 Ṣugbọn ará, ẹnyin kò si ninu òkun-
kun, ti ọjọ na yio fi de bá nyin bi olè.
5 Nitori gbogbo nyin ni ọmọ imọlẹ, ati
ọmọ ọsán: awa kì iṣe ti oru, ati ti òkunkun.
6 Nitorina ẹ máṣe jẹ ki a sùn, bi awọn
ẹlomiran ti nṣe; ṣugbọn ẹ jẹ ki a mã ṣọra
ki a si wà li airekọja.
7 Nitori awọn ti nsùn, nwọn ama sùn li
oru; ati awọn ti nmọtipara, nwọn ama
mọtipara li oru.
8 Ṣugbọn ẹ jẹ ki awa, ti iṣe ti ọsán, ki a
mã wà li airekọja, ki a mã gbé awo-àiya
igbagbọ́ ati ti ifẹ wọ̀; ati fun aṣibori irin,
ireti igbala.
9 Nitoripe Ọlọrun kò yàn wa fun ibinu,
bikoṣe lati ni igbala nipasẹ Jesu Kristi
Oluwa wa,
10 Ẹniti o kú fun wa, pe bi awa ba jí
tabi bi awa ba sùn, ki a le jùmọ wà lãye
pẹlu rẹ̀.
11 Nitorina ẹ jùmọ mã gbà ọmọnikeji
nyin niyanju, ki ẹ si ma kọ́ ọmọnikeji nyin,
gẹgẹ bi ẹnyin ti nṣe pẹlu.
12 Awa si mbẹ̀ nyin, ará, ki ẹnyin ki o
mọ̀ awọn ti nṣiṣẹ larin nyin, ti nwọn si nṣe
olori nyin nipa ti Oluwa, ti nwọn si nkìlọ
fun nyin;
13 Ki ẹ si mã buyìn fun wọn gidigidi
nipa ifẹ nitori iṣẹ wọn. Ẹ si mã wà li
alafia si ara nyin.
14 Ṣugbọn awa mbẹ̀ nyin, ará, ki ẹ mã
kìlọ fun awọn ti iṣe alurekọja, ẹ mã tù
awọn alaile àiya ninu, ẹ mã ràn awọn alai-
lera lọwọ, ẹ mã mu sũru fun gbogbo enia.
15 Ẹ kiyesi i, ki ẹnikẹni ki o máṣe fi
buburu gbẹsan buburu si ẹnikẹni; ṣugbọn
ẹ mã lepa eyi ti iṣe rere nigbagbogbo, larin
ẹnyin tikara nyin, ati si gbogbo enia.
16 Ẹ mã yọ̀ nigbagbogbo.
17 Ẹ mã gbadura li aisimi.
18 Ẹ mã dupẹ nitori ohun gbogbo: ni-
tori eyi ni ifẹ Ọlọrun ninu Kristi Jesu
nitori nyin.
19 Ẹ máṣe pa iná Ẹmí.
20 Ẹ máṣe kẹgan isọtẹlẹ.
21 Ẹ mã wadi ohun gbogbo daju; ẹ dì
eyiti o dara mu ṣinṣin.
22 Ẹ mã takéte si ohùn gbogbo ti iṣe
buburu.
23 Ki Ọlọrun alafia takararẹ̀ ki o si sọ
nyin di mimọ́ patapata; emi si ngbadura
si Ọlọrun ki a le pa gbogbo ẹmí ati ọkàn
ati ara nyin mọ́ li ailabuku titi di igba
wíwa Jesu Kristi Oluwa wa.
24 Olododo li ẹniti o pè nyin, ẹniti yio
si mu u ṣẹ pẹlu.
25 Ará, ẹ mã gbadura fun wa.
26 Ẹ fi ifẹnukonu mimọ́ kí gbogbo awọn
ará.
27 Mo fi nyin bú nipa ti Oluwa pe, ki a
kà Iwe yi fun gbogbo awọn ará mimọ́.
28 Ki ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa ki o
wà pẹlu nyin. Amin.

A kọ Episteli ikini si awọn ara Tessa-
lonika lati Ateni lọ.

Digitized by Google

EPISTELI EKEJI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN ARA TESSALONIKA.

## ORI 1.

PAULU, ati Silfanu, ati Timoteu, si ijọ
Tessalonika, nipa ti Ọlọrun Baba wa,
ati Jesu Kristi Oluwa:
2 Ore-ọfẹ si nyin, ati alafia, lati ọdọ
Ọlọrun Baba wa wá, ati Jesu Kristi
Oluwa.
3 Awa sá di ajigbese lati ma dupẹ lọwọ
Ọlọrun nigbagbogbo nitori nyin, ará, bi o
ti yẹ, nitoripe igbagbọ́ nyin ndàgba gidi-
gidi, ati ifẹ olukuluku gbogbo nyin si ara
nyin di pipọ;
4 Tobẹ̃ ti awa tikara wa nṣogo ninu
nyin ninu ijọ enia Ọlọrun, nitori sũru ati
igbagbọ́ nyin ninu gbogbo inunibini ati
wahalà nyin ti ẹnyin fi àiya rán:
5 Eyiti iṣe àmi idajọ ododo Ọlọrun ti o
daniloju, ki a le kà nyin yẹ fun ijọba Ọlọ-
run, nitori eyiti ẹnyin fi njìya pẹlu:
6 Ohun ododo sá ni nitõtọ fun Ọlọrun
lati fi ipọnju gbẹsan lara awọn ti npọ́n
nyin loju;
7 Ati fun ẹnyin ti a npọ́n loju, simi pẹlu
wa nigba ifarahàn Jesu Oluwa lati ọrun wá
pẹlu awọn angeli rẹ̀ alagbara,
8 Ẹniti yio bù igbẹsan lù awọn ti kò mọ̀
Ọlọrun nipa ọwọ́ iná, ati awọn ti kò gbà
ihin-rere Jesu Kristi Oluwa wa gbọ́:
9 Awọn ẹniti a o fi iparun ainipẹkun
daloro lati iwaju Oluwa lọ, ati lati inu ogo
agbara rẹ̀ lọ;
10 Nigbati on o pada wá lati jẹ ẹni ãyìn
logo lara awọn enia mimọ́ rẹ̀, ati lati jẹ ẹni
ibuyìn fun larin gbogbo awọn ti o gbagbọ́
(nitoripe a ti gbà ẹrí wa gbọ́ larin nyin) li
ọjọ na.
11 Nitorina awa pẹlu ngbadura fun nyin
nigbagbogbo, ki Ọlọrun wa ki o le ka nyin
yẹ si ìpe yi, ki o si mu gbogbo ifẹ inu rere
nipa iṣeun rẹ̀ ṣẹ, ati iṣẹ igbagbọ́ pẹlu
agbara:
12 Ki a le yìn orukọ Jesu Kristi Oluwa
wa logo ninu nyin, ati ẹnyin ninu rẹ̀, gẹgẹ
bi ore-ọfẹ Ọlọrun wa ati ti Jesu Kristi
Oluwa.

## ORI 2.

SUGBỌN awa mbẹ̀ nyin, ará, nipa wíwa
Jesu Kristi Oluwa wa, ati nipa ipejọ
wa sọdọ rẹ̀,
2 Ki àiya ki o máṣe tète pá nyin, tabi
ki ẹru ki o máṣe bà nyin, yala nipa ti ẹmí,
tabi nipa ọ̀rọ, tabi nipa ìwe lati ọdọ wa
wá, bi ẹnipe ọjọ Kristi kù si dẹdẹ.
3 Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o tàn nyin jẹ
nitori ohunkohun; nitoripe ọjọ na ki yio
de, bikoṣepe iṣubu-kuro nì ba tète de na, a
o si fi ẹni ẹ̀ṣẹ nì hàn, ti iṣe ọmọ iparun;
4 Ẹniti nṣe ìdena, ti o si ngbé ara rẹ̀ ga
jù gbogbo ẹniti a npè li Ọlọrun lọ, tabi ti a
ntẹriba fun; bẹ̃ gẹgẹ bi ẹnipe Ọlọrun o joko
ni tempili Ọlọrun, o nfi ara rẹ̀ hàn pe Ọlọ-
run li on.
5 Ẹnyin kò ranti pe, nigbati mo wà pẹlu
nyin, mo ti sọrọ nkan wọnyi fun nyin?
6 Ẹnyin sá mọ̀ ohun ti o da a duro nisi-
siyi ki a le ba fi i hàn li akokò rẹ̀.
7 Nitoripe ohun ijinlẹ ẹ̀ṣẹ ti bẹ̀rẹ si iṣiṣẹ
na: kìki ẹniti ndá a duro yio mã dá a
duro, titi a o fi mu u ti ọ̀na kuro.
8 Nigbana li a o si fi Ẹni buburu nì hàn,
ẹniti Oluwa yio mu ṣegbé nipa ẹmí ẹnu rẹ̀,
ti yio si fi imọlẹ wíwa rẹ̀ parun:
9 Ani on na, ẹniti wíwa rẹ̀ yio ri gẹgẹ bi
iṣẹ Satani nipa agbara gbogbo, ati àmi ati
iyanu eke gbogbo,
10 Ati nipa itanjẹ aiṣododo gbogbo ninu
awọn ti o ṣegbé; nitori ti nwọn kò gbà ifẹ
otitọ, ki a má ba gbà wọn là.
11 Ati nitori eyi, Ọlọrun yio rán ẹ̀tan
lile si wọn, ki nwọn ki o le gbà eke gbọ́:
12 Ki gbogbo awọn ti kò gbà otitọ gbọ́
ṣugbọn ti nwọn ni inu-didùn ninu aiṣo-
dodo, ki o le jẹbi.
13 Ṣugbọn awa di ajigbese lati ma fi ọpẹ́
fun Ọlọrun nigbagbogbo nitori nyin, ará,
olufẹ nipa ti Oluwa, nitoripe li àtetekọṣe

Digitized by Google

Ọlọrun ti yàn nyin si igbala nipa iwẹnumọ́
Ẹmí ati igbagbọ́ otitọ:
14 Nipasẹ eyiti o ti pè nyin nipa ihin-
rere wa, lati gbà ogo nipa Jesu Kristi Oluwa
wa.
15 Nitorina, ará, ẹ duro ṣinṣin, ki ẹ si
di ẹkọ́ wọnni mu ti a ti fi kọ́ nyin, yala
nipa ọ̀rọ, tabi nipa iwe wa.
16 Njẹ nisisiyi ki Jesu Kristi Oluwa wa
tikararẹ̀, ati Ọlọrun, ani Baba wa na, ẹniti
o ti fẹ wa, ti o si ti fi itunu ti kò nipẹkun
ati ireti rere fun wa nipa ore-ọfẹ,
17 Ki o tù nyin li àiya, ki o si fi ẹsẹ nyin
mulẹ ninu ọ̀rọ ati iṣẹ rere gbogbo,

## ORI 3.

LAKOTAN, ará, ẹ mã gbadura fun wa,
ki ọ̀rọ Oluwa le mã sáre li aisi ìdena,
ki o si ma jẹ ãyîn logo, ani gẹgẹ bi o ti ri
lọdọ nyin:
2 Ati ki a le gbà wa lọwọ awọn alainiro-
nu ati awọn ẹni buburu: nitoripe gbogbo
enia kò ni igbãgbọ́.
3 Ṣugbọn olododo li Oluwa, ẹniti yio fi
ẹsẹ nyin mulẹ, ti yio si pa nyin mọ́ kuro
ninu ibi.
4 Awa si ni igbẹkẹle lọdọ Oluwa nitori
nyin, pe ẹnyin ti nṣe, ẹnyin o si mã ṣe
nkan wọnni ti a pa laṣẹ fun nyin.
5 Ki Oluwa ki o si mã ṣe amọ̀na àiya
nyin sinu ifẹ Ọlọrun, ati sinu sũru
Kristi.
6 Awa si fi aṣẹ fun nyin nisisiyi, ará, li
orukọ Jesu Kristi Oluwa wa, ki ẹnyin ki o
yà ara nyin kuro lọdọ olukuluku arakọn-
rin, ẹniti ìrin rẹ̀ kò ṣe dẽdẽ, ti kì iṣe gẹgẹ
bi ìlana ti on ti gbà lọwọ wa.
7 Nitoripe ẹnyin tikara nyin mọ̀ bi
ẹnyin iba ti mã tọ̀ wa lẹhin: nitori awa kò
fi ara wa ṣe ohun aitọ́ kan larin nyin;
8 Bẽli awa kò si jẹ onjẹ ẹnikẹni lasan;
ṣugbọn awa nṣiṣẹ nipa ṣiṣe lãlã ati irora li
ọsán ati li oru, ki awa ki o máṣe ná ẹnikẹni
li owo:
9 Kì iṣe nitoriti awa kò li agbara, ṣu-
gbọn awa nfi ara wa ṣe apẹrẹ fun nyin lati
mã tọ̀ wa lẹhin.
10 Nitori nigbati awa tilẹ wà pẹlu nyin
pãpã, eyi na li awa ti pa laṣẹ fun nyin, pe
bi ẹnikẹni kò ba fẹ iṣẹ-iṣe, kò tọ́ ki o jẹun.
11 Nitori awa gbọ́ pe awọn kan wà ninu
nyin ẹniti ìrin wọn kò ṣe dẽdẽ, awọn ti kò
ṣiṣẹ rara, ṣugbọn nwọn kuku jasi olofófo.
12 Irú awọn ti o ri bẹ̃ li awa paṣẹ fun
nisisiyi, ti a si nkìlọ fun nipa Jesu Kristi
Oluwa wa, pe ki nwọn ki o mã fi ìwa pẹlẹ
ṣiṣẹ, ki nwọn ki o si mã jẹ onjẹ awọn tikara
wọn.
13 Ṣugbọn ẹnyin, ará, ẹ máṣe ṣãrẹ̀ ni iṣẹ
rere iṣe.
14 Bi ẹnikẹni kò ba si gbà ọ̀rọ wa gbọ́
nipa Iwe yi, ẹ ṣàkiyesi i, ki ẹ má si ṣe ba a
kẹgbẹ, ki oju ki o le tì i.
15 Ṣugbọn ẹ máṣe kà a si bi ẹnipe ọtá,
ṣugbọn ẹ mã gbà a niyanju bi arakọnrin.
16 Njẹ ki Oluwa alafia tikararẹ̀ ki o fi
alafia fun nyin nigbagbogbo lọna gbogbo.
Ki Oluwa ki o wà pẹlu gbogbo nyin.
17 Ikí ti Paulu lati ọwọ́ emi tikarami,
eyiti iṣe àmi ninu gbogbo Iwe: bẽni emi
nkọwe.
18 Ki ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa ki o
wà pẹlu gbogbo nyin. Amin.

---

A kọ Episteli keji si awọn ara Tessa-
lonika lati Ateni lọ.

---

# EPISTELI IKINI TI PAULU APOSTELI

SI

# TIMOTEU.

## ORI 1.

PAULU, Aposteli Jesu Kristi, nipa aṣẹ
Ọlọrun Olugbala wa, ati Jesu Kristi
Oluwa, ti iṣe ireti wa;
2 Si Timoteu, ọmọ mi nitõtọ nipa igba-
gbọ́: Ore-ọfẹ, ãnu, ati alafia, lati ọdọ Ọlọ-
run Baba wa wá, ati Jesu Kristi Oluwa wa.
3 Bi mo ti bẹ̀ ọ pe ki o joko ni Efesu,
nigbati emi lọ si Makedonia, ki iwọ ki o le

Digitized by Google

mã paṣẹ fun awọn kan pe, ki nwọn ki o
máṣe kọni li ẹkọ́ miran kan,
4 Ati pe ki nwọn ki o máṣe fiyesi ìtan
asan ati ìtan idile wọnni ti kò li opin, ti
ima rú ìbere soke, jù imuniduro ẹkọ́ Ọlọ-
run lọ ti mbẹ ninu igbagbọ́ : mã ṣe bẹ̃.
5 Ṣugbọn opin ofin ni ifẹ lati ọkàn fun-
fun jade wá, ati ti inu rere, ati igbagbọ́
aiṣẹtan :
6 Kuro ninu eyiti awọn ẹlomiran yà si
apakan, ti nwọn si ti yipada si ọ̀rọkọrọ
asan ;
7 Nwọn nfẹ ṣe olukọ ofin ; oyé ohun ti
nwọn nwi kò yé wọn, tabi ohun ti nwọn
tẹnumọ́.
8 Ṣugbọn awa mọ̀ pe ofin dara, bi enia ba
lò o bi o ti tọ́ si ofin ;
9 A mọ̀ eyi pe, a kò dá ofin silẹ fun olo-
dodo, bikoṣe fun awọn alailofin ati awọn
alaigbọran, fun awọn alaiwabi-Ọlọrun ati
fun awọn ẹlẹṣẹ, fun awọn alaimọ́ ati fun
awọn jagidijagan, fun awọn apa-baba ati
awọn apa-iya, fun awọn apania,
10 Fun awọn àgbere, fun awọn ti nfi
ọkọnrin ba ara wọn jẹ, fun awọn ají-enia,
fun awọn eleke, fun awọn abura eke, ati bi
ohun miran kan ba mbẹ ti o lodi si ẹkọ́ ti
o pé ;
11 Gẹgẹ bi ihin-rere ti o li ogo, ti Ọlọ-
run olubukún, ti a fi le mi lọwọ.
12 Mo si dupẹ lọwọ Jesu Kristi Oluwa
wa, ẹniti o ràn mi lọwọ, nitori ti o kà mi si
olõtọ, ti o fi mi sinu iṣẹ iranṣẹ ;
13 Ni iṣaju ẹniti iṣe asọ̀rọ buburu, ati
aṣenunibini, ati elewu enia : ṣugbọn mo ri
ãnu gbà, nitoriti mo fi aimọ̀ ṣe e ninu
aigbagbọ̀.
14 Ore-ọfẹ Oluwa wa si pọ̀ rekọja pẹlu
igbagbọ́ ati ifẹ, ti mbẹ ni Kristi Jesu.
15 Eyi li ọ̀rọ otitọ, o si yẹ fun itẹwọgbà
gbogbo, pe Kristi Jesu wá si aiye yi lati
gbà ẹlẹṣẹ là ; ninu awọn ẹniti emi ṣe
pàtaki.
16 Ṣugbọn nitori eyi na li emi ṣe ri ãnu
gbà, pe lara mi ṣaju ni ki Jesu Kristi ki o le
fi ipamọra gbogbo hàn, apẹrẹ fun awọn ti
yio gbà a gbọ́ nigba ikẹhin si iye ainipẹkun.
17 Njẹ fun Ọba aiyeraiye, aidibajẹ, airi,
Ọlọrun ọlọ́gbọn nikan, ni ọlá ati ogo wà
fun lai ati lailai. Amin.
18 Aṣẹ yi ni mo pa fun ọ, Timoteu ọmọ,
gẹgẹ bi isọtẹlẹ wọnni ti o ti ṣaju lara rẹ, pe
nipa wọn ki iwọ ki o le mã jà ogun rere ;
19 Mã dì igbagbọ́ mu, ati ọkàn rere ; ti
awọn miran kan ti ṣatì nipa igbagbọ́ nwọn
ṣe ìdalẹ :
20 Ninu awọn ẹniti Himeneu ati Alek
sanderu wà ; awọn ti mo ti fi le Satani
lọwọ, ki a le ba kọ́ wọn ki nwọn ki o má
sọ̀rọ buburu mọ́.

## ORI 2.

NITORINA mo fẹ ṣaju gbogbo rẹ̀, pe ki
a bẹbẹ, ki a gbadura, ki a ṣìpẹ, ati ki
a dupẹ nitori gbogbo enia ;
2 Nitori awọn ọba, ati gbogbo awọn
ijoye ; ki awa ki o le ma rìn aiye ni ida-
kẹjẹ ati li alafia ninu gbogbo ìwa-bi-Ọlọ-
run ati ìwa mimọ́.
3 Nitori eyi li o dara ti o si ṣe itẹwọgbà
li oju Ọlọrun Olugbala wa ;
4 Ẹniti nfẹ lati gbà gbogbo enia là, ati
ki nwọn ki o si wá sinu ìmọ otitọ.
5 Nitoripe Ọlọrun kan, ati onilaja kan
ni mbẹ larin Ọlọrun ati enia, ọkọnrin nã
Kristi Jesu ;
6 Ẹniti o fi ara rẹ̀ ṣe irapada fun gbogbo
enia, lati jẹ ẹrí li akokò ti o yẹ.
7 Ninu eyi ti a yàn mi ṣe oniwasu, ati
aposteli, (otitọ li emi nsọ niti Kristi, emi
kò ṣeke ;) olukọ awọn Keferi ni igbagbọ́
ati nitõtọ.
8 Mo fẹ nitorina ki awọn ọkọnrin ki o
mã gbadura nibi gbogbo, ki nwọn ki o mã
gbé ọwọ́ mimọ́ soke, li aibinu ati li aiṣiye-
meji.
9 Bẹ̃ gẹgẹ pẹlu ni ki awọn obirin ki o fi
aṣọ iwọntunwọnsin ṣe ara wọn li ọṣọ́, pẹlu
itiju ati ìwa airekọja ; ki iṣe pẹlu irun didì,
tabi wura, tabi okuta daradara, tabi iwọṣọ
owo iyebiye ;
10 Ṣugbọn bikoṣe (eyi ti o yẹ fun awọn
obirin ti o jẹwọ ìwabi-Ọlọrun) pẹlu iṣẹ
rere.
11 Jẹ ki obirin ki o ma fi idakẹjẹ ati
iforibalẹ gbogbo kọ́ ẹkọ́.
12 Ṣugbọn emi kò fi aṣẹ fun obirin lati
ma kọni, tabi lati gbà ọlá aṣẹ sori ọkọnrin,
bikoṣepe ki o dakẹjẹ.
13 Nitori Adamu li àtete dá, lẹhin na,
Efa.
14 A kò si tàn Adamu jẹ, ṣugbọn obirin
na, nigbati a tàn a, on li o wà ninu
irekọja.
15 Ṣugbọn a o gbà a là ninu bíbi ọmọ,
bi nwọn ba duro ninu igbagbọ́, ati ifẹ, ati
ninu ìwa mimọ́ pẹlu ìwa airekọja.

## ORI 3.

EYI li ọ̀rọ otitọ, Bi ẹnikan ba fẹ oyè bi-
ṣopu, iṣẹ rere li o nfẹ.
2 Njẹ biṣopu kò le ṣe ẹni ẹgan, bikoṣe

Digitized by Google

ọkọ aya kan, oluṣọra, alairekọja, oniwa
rere, olufẹ alejò ṣiṣe, alãpọn ninu kikọni:
3 Kì iṣe ọmọti, kì iṣe aluni, kì iṣe oni-
wọra nitori ère; bikoṣe onisũru, kì iṣe
alasọ, kì iṣe olojukòkoro;
4 Ẹniti o kawọ ile ara rẹ̀ girigiri, ti o
mu awọn ọmọ rẹ̀ tẹriba pẹlu ìwa àgba
gbogbo;
5 (Nitoripe bi enia kò ba mọ̀ bi ãti ṣe
ikawọ ile ara rẹ̀, on o ha ti ṣe le ṣe itọju
ijọ enia Ọlọrun?)
6 Kì iṣe enia titun, nitoripe ki o má ba
fi irera gbé ara ga, a si ṣubu sinu ẹbi Èṣu.
7 Pẹlupẹlu kò le ṣe aini ihin rere lọdọ
awọn ti mbẹ lode: ki o má ba bọ sinu
ẹ̀gan ati sinu idẹkun Èṣu.
8 Bẹ̃ gẹgẹ ni awọn diakoni kò le ṣe alai-
ni ìwa àgba, kì iṣe ẹlẹnu meji, kì iṣe ẹniti
o fi ara rẹ̀ fun ọti-waini pupọ̀, kì iṣe oni-
wọra nitori ère;
9 Ẹniti ndì ohun ijinlẹ igbagbọ́ mu li
ọkàn funfun.
10 Ki a ri idi awọn wọnyi daju na pẹlu;
nigbana ni ki a jẹ ki nwọn ki o jẹ oyè dia-
koni, bi a ti ri wọn li ailẹgan.
11 Ati bẹ̃li awọn aya wọn kò le ṣe alaini
ìwa àgba, kì iṣe agbadulumọ̀, bikoṣe alaire-
kọja, olõtọ li ohun gbogbo.
12 Ki awọn diakoni ki o jẹ ọkọ obirin
kọ̃kan, ki nwọn ki o ṣe itọju awọn ọmọ wọn,
ati ile ara wọn rere.
13 Nitori awọn ti o lò oyè diakoni rere,
nwọn rà iṣiṣẹ rere fun ara wọn, ati igboiya
nla ni igbagbọ́ ti iṣe ti Kristi Jesu.
14 Nkan wọnyi ni mo kọwe si ọ, emi
nreti ati tọ̀ ọ wá ni lọ̃lọ̃.
15 Ṣugbọn bi mo ba duro pẹ, ki iwọ ki
o le mọ̀ bi iwọ o ti ma lò ara rẹ ni ile Ọlọ-
run, ti iṣe ijọ enia Ọlọrun alãye, opó ati
itisẹ otitọ.
16 Ati li aini ijiyan, titobi ni ohun ijinlẹ
ìwabi-Ọlọrun: a fi Ọlọrun hàn ninu ara,
a da a lare nipa Ẹmí, a ri i lọdọ awọn
angeli, a wasu rẹ̀ fun awọn Keferi, a gbà a
gbọ́ li aiye, a gbà a soke sinu ogo.

## ORI 4.

ṢUGBỌN Ẹmí ti sọ dajudaju pe, ni igba
ikẹhin awọn miran yio lọ kuro ninu
igbagbọ, nwọn o ma fiyesi ẹmí itanjẹ, ati
ẹkọ́ ẹmi èṣu;
2 Nwọn o mã ṣeke ninu agabagebe; ti a
fi irin gbigbona mọ́ li ọkàn;
3 Nwọn o mã dani lẹkun lati gbeyawo,
nwọn o mã paṣẹ lati ma kàwọ ẹran, ti
Ọlọrun ti dá lati ma fi ọpẹ́ gbà lọwọ awọn
ti o gbagbọ́, ti nwọn si mọ̀ otitọ.
4 Nitoripe gbogbo ẹda Ọlọrun li o dara,
kò si ọkan ti a kọ̀, bi a ba fi ọpẹ́ gbà a:
5 Nitori a fi ọ̀rọ Ọlọrun ati adura yà a si
mimọ́.
6 Bi iwọ bà nrán awọn ará leti nkan
wọnyi, iwọ o ṣe iranṣẹ rere ti Jesu Kristi,
ti a tọ́ si ọ̀rọ igbagbọ́ ati ti ẹkọ́ rere, ninu
eyi ti iwọ ti de.
7 Ṣugbọn kọ̀ ìtan asan awọn arugbo
obirin silẹ, ki o si mã lò ara rẹ si ìwabi-
Ọlọrun.
8 Nitoripe ìlo ti ara ère igba diẹ ni:
ṣugbọn ìwabi-Ọlọrun o li ère si ohun gbo-
gbo, o ni ileri aiye ti mbẹ nisisiyi, ati aiye
ti mbọ̀.
9 Eyi li ọ̀rọ otitọ o si yẹ fun itẹwọgbà
gbogbo.
10 Njẹ nitorina li awa nṣe lãlã ati ti a si
njìya ẹ̀gan, nitori ti awa gbẹkẹle Ọlọrun
alãye, ẹniti iṣe Olugbala gbogbo enia, pẹlu-
pẹlu ti awọn ti o gbagbọ́.
11 Nkan wọnyi ni ki iwọ pa laṣẹ ki o si
ma kọ́ni.
12 Máṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o gàn ewe rẹ;
ṣugbọn ki iwọ ki o ṣe apẹrẹ awọn onigba-
gbọ́, ninu ọ̀rọ, ninu ìwa, ninu ifẹ, ninu
ẹmi, ninu igbagbọ́, ninu ìwa funfun.
13 Titi emi o fi de, mã fiyesi iwe kikà,
si igbaniyanju, si ẹkọ́.
14 Máṣe gbagbé ẹ̀bun ti mbẹ lara rẹ, ti a
fifun ọ nipa isọtẹlẹ, pẹlu ifọwọle awọn
àgba.
15 Mã ṣe àṣaro nkan wọnyi; fi ara rẹ
fun wọn patapata; ki ìdagba rẹ ki o le
hàn ninu ohun gbogbo.
16 Mã ṣe itọju ara rẹ ati ti ẹkọ́; mã
duro ninu wọn: nitori ni ṣiṣe eyi iwọ o gbà
ara rẹ là, ati awọn ti ngbọ́ ọ̀rọ rẹ.

## ORI 5.

MÁṢE ba alàgba wi, ṣugbọn ki o mã bá
a lò bi baba; awọn ọdọmọkọnrin bi
arakọnrin;
2 Awọn obirin àgba bi iya; awọn ọmọ-
birin bi arabirin, pẹlu ìwa funfun gbo-
gbo.
3 Bọ̀wọ fun awọn opó ti iṣe opó nitõtọ.
4 Ṣugbọn bi opó kan ba li ọmọ tabi ọmọ
ibatan, jẹ ki nwọn kọ́ tète mã fi ãnu hàn
ninu ile ara wọn, ki nwọn ki o mã ṣe itọju
awọn õbi wọn: nitoripe eyini li o dara, o
si ṣe itẹwọgbà niwaju Ọlọrun.
5 Njẹ ẹniti iṣe opó nitõtọ, ti o ṣe on

Digitized by Google

nikan, a gbẹkẹle Ọlọrun, a si duro ninu
ẹ̀bẹ ati ninu adura lọsán ati loru.
6 Ṣugbọn ẹniti o ba wà ninu aiye jijẹ, o
kú nigbati o wà lãye.
7 Ati ohun wọnyi ni ki iwọ pa laṣẹ, ki
nwọn ki o le ma gbé li ailẹgan.
8 Ṣugbọn bi ẹnikan. kò ba pèse fun ara
rẹ̀, ati pẹlupẹlu fun awọn ará ile rẹ̀, o ti sẹ́
igbagbọ́ na, o burujù alaigbagbọ́ lọ.
9 Máṣe gbà opó kan sinu ẹgbẹ na li aito
ẹni ọgọta ọdún, ti o si ṣepe obirin ọkọ kan
li o ti ṣe ri,
10 Ẹniti a ròhin rẹ̀ ni iṣẹ rere; bi o ba
ṣe onitọ́ ọmọ, bi o ba mu alejò wọ̀, bi o ba
wẹ̀ ẹsẹ awọn enia mimọ́, bi o ba ràn awọn
olupọnju lọwọ, bi o ba ṣepe o fi aisimi tọ̀
iṣẹ rere gbogbo lẹhin.
11 Ṣugbọn kọ̀ awọn ọmọbirin opó: nito-
ripe nigbati nwọn ba bẹ̀rẹ si iyipada kuro
niti Kristi, nwọn o fẹ gbeyawo;
12 Ti nwọn njẹbi, nitoriti nwọn ti ṣá
igbagbọ́ wọn iṣaju tì.
13 Ati pẹlupẹlu nwọn bẹ̀rẹ si iṣe imẹlẹ,
nwọn rìn kiri lati ile de ile; ki iṣe kìki
imẹlẹ nikan, ṣugbọn onisọkusọ pẹlu ati
olofófo, nwọn nsọ ohun ti kò yẹ ni sisọ.
14 Nitorina mo fẹ ki awọn ọmọbirin ki
o gbeyawo, ki nwọn ki o bímọ, ki nwọn o
ma ṣọ ile, ki nwọn ki o máṣe fi àye fun
awọn ọtá lati mã sọrọ ẹ̀gan.
15 Nitoriti awọn ẹlomiran ti yipada si
apakan na si Satani.
16 Bi ọkọnrin kan tabi obirin kan ti o
gbagbọ́ ba ni awọn opó, ki nwọn ki o ma
ràn wọn lọwọ, ki a má si di ẹrù le ijọ, ki
nwọn ki o le ma ràn awọn ti iṣe opó nitõtọ
lọwọ.
17 Awọn alàgba ti o ṣe itọju rere ni ki a
kà yẹ si ọlá igba meji, pẹlupẹlu awọn ti o
ṣe lãlã ninu ọ̀rọ ati ni kikọni.
18 Nitoriti iwe mimọ́ wipe, Iwọ kò
gbọdọ dì malu ti ntẹ̀ ọkà li ẹnu. Ati pe,
Alagbaṣe yẹ fun ọ̀ya rẹ̀.
19 Máṣe gbà ẹ̀sun si alàgba kan, bikoṣe
li ẹnu ẹlẹri meji tabi mẹta.
20 Ba awọn ti o ṣẹ̀ wi niwaju gbogbo
enia, ki awọn iyokù pẹlu ki o le bẹ̀ru.
21 Mo fi aṣẹ fun ọ niwaju Ọlọrun, ati
Jesu Kristi Oluwa, ati awọn angeli ayanfẹ,
ki iwọ ki o fiyesi nkan wọnyi, li aiṣojusaju
fun ọkan jù ekeji lọ; máṣe fi ègbe ṣe ohun-
kohun.
22 Máṣe yára fi ọwọ́ le ẹnikẹni, bẽni ki
o máṣe lọ́wọ ninu ẹ̀ṣẹ ẹnikan: pa ara rẹ
mọ́ ni ìwa funfun.
23 Máṣe mu omi mọ, ṣugbọn ki o mã lò
ọti-waini diẹ nitori inu rẹ, ati nitori ailera
rẹ igbakugba.
24 Ẹ̀ṣẹ ẹlomiran a ṣí silẹ tẹlẹ, a ṣaju lọ
sinu idajọ; ati ti ẹlomiran a mã tọ̀ ọ
lẹhin.
25 Bẹ̃ gẹgẹ pẹlu, awọn iṣẹ rere ẹlomiran
a hàn ṣaju; ati awọn ti kò si ri bẹ̀, kò le
fi ara sin.

## ORI 6.

IYE awọn ti iṣe ẹrú ti mbẹ ninu ìsin, ki o
kà awọn oluwa ara wọn yẹ si iyìn gbo-
gbo, ki orukọ Ọlọrun ati ẹkọ́ rẹ̀ ki o máṣe
di isọ̀rọ òdi si.
2 Ati awọn ti o si ni oluwa onigbagbọ́,
ki nwọn ki o máṣe gàn wọn, nitoriti nwọn
iṣe arakọnrin; ṣugbọn ki nwọn kuku mã
sìn wọn, nitoripe onigbagbọ́ ati olufẹ ni
nwọn, alabapin ore na. Nkan wọnni ni ki
iwọ mã kọ́ni ki o si mã ṣe afiyesi.
3 Bi ẹnikẹni ba si kọ́ni ni omiran, ti kò
si fi ìmọ si ọ̀rọ rere, ọ̀rọ Jesu Kristi Oluwa
wa, ati si ọ̀rọ ẹkọ́ ti iṣe gẹgẹ bi ìwabi-
Ọlọrun.
4 On ṣiwère, kò mọ̀ ohun kan, bikoṣe
ati mã ṣe awari ère ati ìja ọ̀rọ, nipa eyi ti
ilara, ìja, ẹfẹ̀, igunbẹrẹ ọ̀rọ buburu, ti ijade
wá.
5 Ayipo ijiyan awọn enia elẽri ọkàn, ti
kò si ni otitọ, nwọn ṣebi ìjere ni ìwabi-
Ọlọrun: lọdọ irú awọn wọnni, fà ara yọ
kuro.
6 Ṣugbọn ìwabi-Ọlọrun pẹlu itẹlọrùn ère
nla ni.
7 Nitori awa kò mu ohun kan wá si aiye
yi, o si daniloju pe, awa kì yio si le mu
ohun kan jade lọ.
8 Bi a ba si li onjẹ ti on ti aṣọ, ki eyini
ki o tẹ́ wa lọrùn.
9 Ṣugbọn awọn ti nfẹ di ọlọrọ̀ ama bọ́
sinu idanwò ati idẹkun, ati sinu wère ifẹ-
kufẹ pipọ ti ipanilara, ti si nrì enia sinu
iparun ati egbé.
10 Nitoripe ifẹ owo ni gbòngbo ìwa bu-
buru gbogbo: eyiti nigbati ẹlomiran nfi
ojukòkoro wá kiri, a ti tàn wọn jẹ kuro
ninu igbagbọ́, nwọn si fi ibinujẹ pupọ̀ gún
ara wọn li ọ̀kọ.
11 Ṣugbọ́n iwọ, Enia Ọlọrun, sá fun
nkan wọnyi; ki o si ma tọ̀ ododo, ìwabi-
Ọlọrun, igbagbọ́, ifẹ, sũru, ìwa tutù lẹhin.
12 Mã jà ìja rere ti igbagbọ́, fi ọwọ́ le
ìye ainipẹkun, nibiti a gbé pè ọ si pẹlu, ti
iwọ si ṣe ijẹwọ rere niwaju ẹlẹri pupọ̀.
13 Mo fi aṣẹ fun ọ niwaju Ọlọrun, ti nsọ
ohun gbogbo di ãye, ati niwaju Jesu Kristi,

Digitized by Google

ẹni, niwaju Pontiu Pilatu, ti o jẹri ijẹwọ
rere;
14 Ki iwọ ki o pa aṣẹ yi mọ́ li ailabawọn,
li ainibawi, titi ifarahàn Jesu Kristi Oluwa
wa:
15 Ni igba tirẹ̀, ẹniti yio fihàn, Olubu-
kún, ati Alagbara na kanṣoṣo, Ọba awọn
ọba, ati Oluwa awọn oluwa;
16 Ẹniti on nikanṣoṣo ni aikú, o tẹ̀do
sinu imọlẹ ti ẹnikan kò le suumọ; ẹniti
ẹnikan kò ri rí, bẽli a ko le ri i: ti ọlá ati
agbara mbẹ fun lailai. Amin.
17 Kìlọ fun awọn ti o lọrọ̀ li aiye yi, ki
nwọn ki o máṣe gberaga, ki nwọn ki o
máṣe gbẹkẹle ọrọ̀ aidaniloju, bikoṣe le Ọlọ-
run alãye, ti nfi ohun gbogbo fun wa ni
lilò lọpọlọpọ;
18 Ki nwọn ki o mã ṣe rere, ki nwọn ki
o mã pọ̀ ni iṣẹ rere, ki nwọn mura lati
pínfunni, ki nwọn ni ifẹ ati ṣe idapọ:
19 Ki nwọn ki o mã tò iṣura ipilẹ rere
jọ fun ara wọn dè igba ti mbọ̀, ki nwọn ki
o le fi ọwọ́ le ìye ainipẹkun.
20 Timoteu, pa eyi ti a fi ṣú ọ nì mọ́,
mã yẹ̀ ọ̀rọ asan silẹ, ọ̀rọkọrọ, ati ìmọ ijiyan
ọ̀rọ ti a fi eke pè bẽ:
21 Ti awọn ẹlomiran jẹwọ ti nwọn si
ṣìna ninu igbagbọ́. Ki ore-ọfẹ ki o wà
pẹlu rẹ. Amin.

Episteli ikini yi si Timoteu li a kọ lati Laodikea wá, ti iṣe olú ilu ti Frigia Pakatiana.

EPISTELI EKEJI TI PAULU APOSTELI

SI

# TIMOTEU.

## ORI 1.

PAULU, Aposteli Jesu Kristi nipa ifẹ
Ọlọrun, gẹgẹ bi ileri ìye ti mbẹ ni
Kristi Jesu,
2 Si Timoteu, ọmọ mi olufẹ ọwọn: Ore-
ọfẹ, ãnu, ati alafia, lati ọdọ Ọlọrun Baba
wá, ati Jesu Kristi Oluwa wa.
3 Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun, ti emi nsìn lati
ọdọ awọn baba mi wá ninu ọkàn funfun,
pe li aisimi li emi nṣe iranti rẹ ninu adura
mi loru ati lọsán;
4 Gidigidi li emi nfẹ ri oju rẹ, ti emi
nṣe iranti omije rẹ, ki a le fi ayọ̀ kún mi ni
inu;
5 Nigbati mo ba ranti igbagbọ́ ailẹtan ti
mbẹ ninu rẹ, ti o tète wà ninu Loide iyanla
rẹ, ati ninu Eunike iya rẹ; emi si mọ̀ li
ọkàn mi pe, o mbẹ ninu rẹ pẹlu.
6 Nitorina mo rán ọ leti, ki iwọ ki o rú
ẹ̀bun Ọlọrun, ti mbẹ ninu rẹ soke nipa
ifọwọle mi.
7 Nitoripe Ọlọrun kò fun wa ni ẹmí
ibẹru; bikoṣe ti agbara, ati ti ifẹ, ati ti
inu ti o yè koro.
8 Nitorina ki iwọ ki o máṣe tiju ẹrí
Oluwa wa, tabi ti emi ondè rẹ̀: ṣugbọn ki
iwọ ki o ṣe alabapin ninu iponju ihin-rere
na gẹgẹ bi agbara Ọlọrun;
9 Ẹniti o ti gbà wa là, ti o si ti fi ìpe
mimọ́ pè wa, ki iṣe nipa iṣẹ ti wa, ṣugbọn
nipa ipinnu ati ore-ọfẹ ara rẹ̀, ti o ti fifun
wa nipa Kristi Jesu ki aiye ki o to ṣẹ̀,
10 Ṣugbọn a fihàn nisisiyi nipa ifarahàn
Jesu Kristi Olugbala wa, ẹniti o pa ikú rẹ́,
ti o si mu ìye ati aidibajẹ wá si imọlẹ
nipasẹ ihin-rere:
11 Ninu eyi li a yàn mi ṣe oniwasu, ati
aposteli, ati olukọ awọn Keferi.
12 Nitori eyiti emi ṣe njìya nkan wọnyi:
ṣugbọn oju kò tì mi: nitori emi mọ̀ ẹniti
emi gbagbọ́, o si da mi loju pe, on le pa
ohun ti mo fi le e lọwọ mọ́ titi di ọjọ nì.
13 Dì apẹrẹ ọ̀rọ ti o yè koro nì mu, ti
iwọ ti gbọ́ lọdọ mi, ni igbagbọ́ ati ifẹ ti
mbẹ ninu Kristi Jesu.
14 Ohun rere nì ti a ti fi le ọ lọwọ, pa a
mọ́ nipa Ẹmí Mimọ́ ti mbẹ ninu wa.
15 Eyi ni iwọ mọ̀, pe gbogbo awọn ti o
wà ni Asia yipada kuro lẹhin mi; ninu

Digitized by Google

awọn ẹniti Figellu ati Hermogene gbé
wà.
16 Ki Oluwa ki o fi ãnu fun ile Onesi-
foru; nitori ti ima tù mi ni inu nigba
pupọ̀, oju ẹ̀wọn mi kò si tì i:
17 Ṣugbọn nigbati o wà ni Romu, o wá
mi li aisimi, o si ri mi.
18 Ki Oluwa ki o fifun u ki o le ri ãnu
Oluwa li ọjọ nì: ati ninu iye ohun ti o ṣe
iranṣẹ fun mi ni Efesu, iwọ tikararẹ mọ̀
dajudaju.

## ORI 2.

NITORINA, iwọ ọmọ mi, mu ara le ninu
ore-ọfẹ ti mbẹ ninu Kristi Jesu.
2 Ati ohun wọnni ti iwọ ti gbọ́ lọdọ mi
pẹlu ọ̀pọlọpọ ẹlẹri, awọn na ni ki iwọ fi le
awọn olõtọ enia lọwọ, awọn ti yio le ma kọ́
awọn ẹlomiran pẹlu.
3 Nitorina iwọ fi ọkàn rán iṣoro, bi
ọmọ-ogun rere Jesu Kristi.
4 Kò si ẹniti njàgun ti ifi ohun aiye yi
kọ́ ara rẹ̀ lọwọ; ki o le mu ẹniti o yàn a li
ọmọ-ogun ni inu dùn.
5 Bi ẹnikẹni ba njà ajaṣẹ pẹlu, a kì iti
dé e li ade, bikoṣepe o ba jà li aiṣe erú.
6 Agbẹ ti o nṣiṣẹ, kò le ṣe aitète mu
ninu eso wọnni.
7 Gbà ohun ti emi nsọ rò; ki Oluwa ki
o fun ọ li oyé ninu ohun gbogbo.
8 Ranti pe Jesu Kristi ti inu irú ọmọ
Dafidi li a jinde kuro ninu okú gẹgẹ bi
ihin-rere mi:
9 Ninu eyi ti emi nṣe wahalà, bi oluṣe
buburu de inu ìde; ṣugbọn a kò dè ọ̀rọ
Ọlọrun.
10 Nitorina mo fi àiya rán ohun gbogbo
nitori awọn ayanfẹ, ki awọn pẹlu ki o le ni
igbala ti mbẹ ninu Kristi Jesu pẹlu ogo
ainipẹkun.
11 Ọ̀rọ otitọ li eyi: nitoripe bi awa ba
bá a kú, awa o si bá a yè:
12 Bi awa ba jìya, awa o si jọba pẹlu rẹ̀:
bi awa ba sẹ́ ẹ, on o si sẹ́ wa pẹlu:
13 Bi awa kò ba gbagbọ́, ṣugbọn on duro
li olõtọ: on kò le sẹ́ ara rẹ̀.
14 Nkan wọnyi ni ki o ma rán wọn leti,
mã kìlọ fun wọn niwaju Oluwa pe, ki nwọn
ki o máṣe jijà ọ̀rọ ti kò nilári, ti ima yi
awọn ti o gbọ́ po.
15 Ṣe aṣaro ati fi ara rẹ hàn li ẹniti o pé
ninu Ọlọrun, aṣiṣẹ́ ti kò ni oju tití ninu, ti
o npín ọ̀rọ otitọ bi o ti tọ́ gẹ.
16 Ṣugbọn mã yẹ̀ ọ̀rọ asan ati ọ̀rọ isọ-
kusọ wọnni silẹ: nitoriti nwọn o ma pọ̀ si
aiwabi-Ọlọrun siwaju.
17 Ọ̀rọ wọn yio si ma jẹ bi egbò kikẹ̀:
ninu awọn ẹniti Himeneu ati Filetu wà;
18 Awọn ẹniti o ti ṣina nipa ti otitọ, ti
nwipe ajinde ti kọja na; nwọn si bì igba-
gbọ́ awọn ẹlomiran ṣubu.
19 Ṣugbọn ipilẹ Ọlọrun duro ṣinṣin, o ni
àmi èdidi yi, Oluwa mọ̀ awọn ti iṣe tirẹ̀.
Ati pẹlu, Ki olukuluku ẹniti o jẹwọ orukọ
Kristi ki o kuro ninu ẹ̀ṣẹ.
20 Ṣugbọn ninu ile nla, kì iṣe kìki ohun-
èlo wura ati ti fadaka nikan ni mbẹ nibẹ̀,
ṣugbọn ti igi ati ti amọ̀ pẹlu; ati omiran
si ọlá, ati omiran si ailọlá.
21 Bi ẹnikẹni ba wẹ̀ ara rẹ̀ nù kuro ninu
wọnyi, on o jẹ ohun-èlo si ọlá, ti a yà si
ọ̀tọ, ti o si yẹ fun ìlo bãle, ti a si ti pèse
silẹ si iṣẹ rere gbogbo.
22 Mã sá fun ifẹkufẹ ewe pẹlu: ṣugbọn
mã tọ̀ ododo, igbagbọ́, ifẹ, alafia lẹhin, pẹlu
awọn ti nkepè Oluwa lati ọkàn funfun jade
wá.
23 Ṣugbọn ìbere wère ati ti alaini ẹkọ́ ni
ki o yẹ̀, iwọ sa mọ̀ pe nwọn ama dá ìja silẹ.
24 Iranṣẹ Oluwa kò si gbọdọ jà; bikoṣe
pe ki o ma ṣe pẹlẹ si enia gbogbo, ki o
mura ati kọ́ni, ki o mu sũru,
25 Ninu ìwa tutù, ki o ma kọ́ awọn
oṣòdi; bi bọya Ọlọrun yio fun wọn ni iro-
nupiwada si ijẹwọ otitọ;
26 Ati pe ki nwọn ki o le sọji kuro ninu
idẹkun Eṣu, awọn ti a ti dì ni igbekun lati
ọwọ́ rẹ̀ wá nipa ifẹ rẹ̀.

## ORI 3.

ṢUGBỌN eyi ni ki iwọ ki o mọ̀, pe ni
ikẹhin ọjọ igba ewu yio de.
2 Nitori awọn enia yio di olufẹ ara wọn,
olojukòkoro, afunnu, aṣefẹ́fe, asọ̀rọ òdi si
Ọlọrun, aṣaigbọran si õbi, alailọpẹ, alaimọ́,
3 Alaini ifẹ ẹda, ọ̀dalẹ, asùnni eke, alai-
farabalẹ, amubina, alainifẹ si ohun rere,
4 Afinihàn, agídi, agberaga, olufẹ afẹ́-
ṣiṣe jù olufẹ Ọlọrun lọ;
5 Nwọn ni afarawe ìwabi-Ọlọrun, ṣu-
gbọn nwọn sẹ́ agbara rẹ̀: lọdọ irú awọn
wọnni ni ki o yipada kuro.
6 Nitori ninu irú eyi li awọn ti nrakò
wọ̀ inu ile, ti nwọn si ndì awọn obirin aṣi-
wère ni igbẹsin, ti a dì ẹrù ẹ̀ṣẹ rù, ti a si
nti ipa onirũru ifẹkufẹ fà kiri,
7 Nwọn nkọ́ ẹkọ́ titi, nwọn kò si le de
ìmọ otitọ.
8 Ṣugbọn gẹgẹ bi Janesi ati Jamberi ti
kọju òdi si Mose, bẹ̃li awọn wọnyi kọju
òdi si otitọ: awọn enia oninu idibajẹ, alai-
nidajọ nipa ti igbagbọ́.

Digitized by Google

9 Ṣugbọn nwọn kì yio lọ jù bẽ̀ lọ: nitori
wère wọn o hàn fun gbogbo enia gẹgẹ bi ti
nwọn ti ri.
10 Ṣugbọn iwọ ti mọ̀ ẹkọ́ mi perepere,
ìwa aiye mi, ipinnu, igbagbọ́, ipamọra,
ifẹni, sũru,
11 Inunibini, wahalà gbogbo ti o bá mi
ni Antioku, ni Ikonioni ati ni Listra; inu-
nibini ti mo fi ara gbà: ṣugbọn kuro ninu
gbogbo wọn Oluwa yọ mi.
12 Nitõtọ, gbogbo awọn ẹniti o si fẹ mã
wà ni ìwabi-Ọlọrun ninu Kristi Jesu, yio fi
ara gbà inunibini.
13 Ṣugbọn awọn enia buburu, ati awọn
ẹlẹtàn yio mã buru lọ siwaju, nwọn o mã
tànnijẹ, nwọn o si wà ninu atitàn.
14 Ṣugbọn iwọ duro ninu nkan wọnni ti
iwọ ti kọ́, ti a si ti fi oju rẹ dá ṣáṣa, ki iwọ
ki o si mọ̀ ọdọ ẹniti iwọ gbé kọ́ wọn;
15 Ati pe lati igba ọmọde wá ni iwọ ti
mọ̀ iwe mimọ́, ti o le mu ọ di ọlọ́gbọn si
igbala nipasẹ igbagbọ́ ninu Kristi Jesu.
16 Gbogbo iwe mimọ́ li a fi funni nipasẹ
imísi Ọlọrun, o si ni ère fun ẹkọ́, fun iba-
niwi, fun itọ́ni, fun ikọ́ni li ododo:
17 Ki enia Ọlọrun ki o le pé, ti a ti
mura silẹ patapata fun iṣẹ rere gbogbo.

ORI 4.

NITORINA mo kìlọ fun ọ niwaju Ọlọrun,
ati Jesu Kristi Oluwa, ẹniti yio ṣe
idajọ alãye ati okú nigba ifarahàn rẹ̀ ati
ijọba rẹ̀;
2 Wasu ọ̀rọ na; mã ṣe aisimi li akokò, ati
li aiṣe akokò; mã fi ipamọra ati ẹkọ́ gbogbo
baniwi, mã fi ṣe itọ́ni, mã fi gbàni niyanju.
3 Nitoripe ìgba yio de, ti nwọn kì yio
duro si ẹkọ́ ti o yè koro; ṣugbọn nipa ifẹ-
kufẹ ara wọn, ni nwọn o lọ ikó olukọ jọ
fun ara wọn, eleti ririn;
4 Nwọn o si yi etí pada kuro ninu otitọ,
nwọn o si yipada sinu ìtan asan.
5 Ṣugbọn iwọ mã ṣọra ninu ohun gbo-
gbo, mã fi ori tì ipọnju, mã ṣe iṣẹ ti oniwã-
su kiri, fi idi ìsin iṣẹ iranṣẹ rẹ hàn.
6 Nitori emi mura tan lati fi mi ṣe itọrẹ,
ìgba alọ mi si sunmọ etile.
7 Emi ti jà ìja rere, emi ti pari ipa ìlana
mi, emi ti pa igbagbọ́ mọ́:
8 Lati isisiyi lọ a ti fi ade ododo lelẹ fun
mi, ti Oluwa, onidajọ ododo, yio fifun mi li
ọjọ na, kì si iṣe kìki emi nikan, ṣugbọn ati
fun gbogbo awọn pẹlu ti o fẹ ifarahàn rẹ̀.
9 Làkaka lati tọ̀ mi wá nisisiyi:
10 Nitori Dema ti kọ̀ mi silẹ lọ, o nfẹ
aiye isisiyi, o si lọ si Tessalonika; Kres-
keni si Galatia, Titu si Dalmatia.
11 Luku nikan li o kù pẹlu mi. Mu
Marku wá pẹlu rẹ: nitori o ṣe anfani fun
mi fun iṣẹ iranṣẹ.
12 Tikiku ni mo rán lọ si Efesu.
13 Aṣọ igbòjo ti mo fi silẹ ni Troa lọdọ
Karpu, nigbati iwọ ba mbọ̀ mu u wá, ati
iwe wọnni, pẹlupẹlu iwe-awọ wọnni.
14 Aleksanderu alagbẹdẹ bàba ṣe mi ni
buburu pupọ̀: Oluwa yio san a fun u gẹgẹ
bi iṣẹ rẹ̀:
15 Nipasẹ ẹniti ki iwọ ki o mã ṣọra pẹlu;
nitoriti o ṣe ìdena si iwasu wa pupọ̀.
16 Li àtetekọ dahùn mi kò si ẹniti o
duro tì mi, ṣugbọn gbogbo enia li o kọ̀ mi
silẹ: mo gbadura ki a máṣe kà a si wọn li
ọrùn.
17 Ṣugbọn Oluwa duro tì mi, o si gbà mi
niyanju; pe nipasẹ mi ki a le fi iwãsu na
hàn li ahàntan, ati pe ki gbogbo awọn
Keferi ki o le gbọ́: a si gbà mi kuro li ẹnu
kiniun nì.
18 Oluwa yio si mã yọ mi kuro ninu iṣẹ
buburu gbogbo, yio si mã pa mi mọ́ titi di
ijọba rẹ̀ ọrun: ẹniti ogo wà fun lai ati lai-
lai. Amin.
19 Kí Priska ati Akuila, ati awọn ará ile
Onesiforu.
20 Erastu joko ni Korinti: ṣugbọn Tro-
fimu ni mo fi silẹ ni Mileto li aisan.
21 Làkaka lati tọ̀ mi wá ki o to di ìgba
otutù. Eubulu kí ọ, ati Pudeni, ati Linu,
ati Klaudia, pẹlu awọn arakọnrin gbogbo.
22 Jesu Kristi Oluwa ki o wà pẹlu ẹmí
rẹ. Ore-ọfẹ ki o wà pẹlu nyin. Amin.

---

Episteli ekeji yi si Timoteu, ti àtetekọ
fi jẹ bişopu ijọ Efesu, li a kọ lati
Romu wá, nigbati a mu Paulu wá
siwaju Nero lẹ̀keji.

Digitized by Google

## EPISTELI TI PAULU APOSTELI

SI

# TITU.

### ORI 1.

PAULU, iranṣẹ Ọlọrun, ati Aposteli Jesu
Kristi, gẹgẹ bi igbagbọ́ awọn ayanfẹ
Ọlọrun, ati ijẹwọ otitọ ti mbẹ nipa ìwabi-
Ọlọrun;
2 Ni ireti ìye ainipẹkun, ti Ọlọrun, ti
kì iṣe eke, ti ṣe ileri ṣaju ipilẹṣẹ aiye;
3 Ṣugbọn nigba akokò tirẹ̀ o si fi ọ̀rọ rẹ̀
hàn nipasẹ iwasu, ti a fi ṣú mi gẹgẹ bi ofin
Ọlọrun Olugbala wa;
4 Si Titu, ọmọ mi nitõtọ nipa ti igbagbọ́
ti o wọpọ̀: Ore-ọfẹ, ãnu, ati alafia, lati ọdọ
Ọlọrun Baba wá ati lati ọdọ Oluwa Jesu
Kristi Olugbala wa.
5 Nitori idi eyi ni mo ṣe fi ọ silẹ ni
Krete, ki iwọ ki o le mã tún ohun gbogbo
ṣe ti o kù li aiṣe, ki o si mã fi alàgba jẹ
olori si olukuluku ilu, bi mo ti làna silẹ
fun ọ:
6 Bi ẹnikan ba ṣe alailẹgan, ọkọ aya
kan, ti o ni onigbagbọ́ ọmọ, ti a kò fi sùn
nipasẹ wọbia, tabi agídi.
7 O yẹ ki biṣopu jẹ alailẹgàn, bi iriju
Ọlọrun; li aifẹ tinu ẹni, li aitète binu, li
aiṣe ọmọti, li aiṣe aluni, li aiṣe oniwọra
nitori ère;
8 Bikoṣe olufẹ alejò ṣiṣe, olufẹ awọn
enia rere, alairekọja, olõtọ, mimọ́, iwọn-
tun-wọnsin;
9 Ti o ndì ọ̀rọ otitọ mu ṣinṣin bi ati kọ́
ọ, nipa ẹkọ́ ti o yè, ki on ki o le ma gbàni
niyanju, ati ki o le fi oyé yé awọn alariwisi
enia.
10 Nitoripe awọn agídi ati awọn asọ̀rọ
asan, ati ẹlẹtàn pupọ̀ ni mbẹ, pọlupẹlu
ninu awọn akọla:
11 Ẹnu ẹniti a kò le ṣe aidaduro, awọn
ẹniti nyi gbogbo ile-ile po, ti nwọn nkọ́
ohun wọnni ti kò yẹ, nitori èrekere ẹgbin.
12 Ọkan ninu awọn tikara wọn na, ani
ọkan ninu awọn woli wọn, o ni, Eleke ni
awọn ará Krete nigbagbogbo, ẹranko
buburu, onilọra ikùn.
13 Otitọ li ẹrí yi. Nitorina ba wọn wi
nigbangba, ki nwọn ki o le yè ni igbagbọ́;
14 Máṣe fiyesi ìtan asan ti awọn Ju, ati
aṣẹ enia ti iyi-ni pada kuro ninu otitọ.
15 Fun awọn oninu funfun, ohun gbogbo
ni funfun: ṣugbọn fun awọn ti iṣe alaimọ́
ti si iṣe alaigbagbọ́ kò si ohun ti iṣe funfun;
ṣugbọn ati inu ati ọkàn wọn aimọ́ ni.
16 Nwọn jẹwọ pe nwọn mọ̀ Ọlọrun; ṣu-
gbọn nipa iṣẹ nwọn nsẹ́ ẹ, nwọn jẹ ẹni irira,
ati alaigbọran, ati ninu iṣẹ rere gbogbo
alainilari.

### ORI 2.

ṢUGBỌN iwọ mã sọ ohun ti o yẹ si ẹkọ́
ti o yè:
2 Ki awọn àgba ọkọnrin ki o mã ṣe olu-
ṣọra, olõtọ, alairekọja, ki nwọn ki o yè ni
igbagbọ́, ni ifẹ, ni sũru.
3 Awọn àgba obirin pẹlu, ki nwọn ki o
mã hù ìwa ti o yẹ si ìwa mimọ́, li aiṣe olu-
fisùn eke, li aiṣe ọmọti-waini pupọ̀, oluko
ohun rere;
4 Ki nwọn ki o le mã kọ́ awọn ọmọbirin
lati mã ṣọra, lati mã fẹ awọn ọkọ wọn, ati
lati mã fẹ awọn ọmọ wọn,
5 Lati ṣe ọlọ́gbọn, lati ṣe mimọ́, ẹniti
yio mã gbé ile, ẹni rere, a gbà ti awọn ọkọ
wọn gbọ́, ki ọ̀rọ Ọlọrun ki o máṣe ni isọ̀rọ
òdi si.
6 Awọn ọdọmọkọnrin pẹlu ni ki iwọ ki
o gbà niyanju, lati ṣe airekọja.
7 Ninu ohun gbogbo mã fi ara rẹ hàn li
apẹrẹ iṣẹ rere: ninu ẹkọ́ mã fi aiṣebajẹ hàn,
ìwa àgba, ìwa otitọ,
8 Ọrọ ti o yè, ti a kò le da lẹbi; ki oju
ki o tì awọn ti o wà ni ipa ilòdi, li aini
ohun buburu kan lati wi si nyin.
9 Gbà awọn ẹrú niyanju lati mã gbà ti
awọn oluwa wọn gbọ́, ki nwọn ki o si mã
mu wọn ninu dùn gidigidi ninu ohun gbo-
gbo; li aipada dahùn;
10 Li aiṣe iréjẹ bikoṣe lati fi gbogbo
otitọ rere hàn; ki nwọn ki o le mã ṣe ẹkọ́

Digitized by Google

Ọlọrun Olugbala wa li ọṣọ́ ninu ohun
gbogbo.
11 Nitori ore-ọfẹ Ọlọrun ti o mu ìgbala
fun gbogbo enia wá, ti hàn,
12 O nkọ́ wa pe, ni sisẹ́ aiwa bi-Ọlọrun
ati ifẹkufẹ aiye, ki a le ma gbé ni ìwa aire-
kọja, ìwa ododo, ati ìwabi-Ọlọrun li aiye
isisiyi;
13 Ki a mã woye ireti ti o ni ibukún,
ati ifihàn ti o li ogo ti Ọlọrun ti o tobi, ati
ti Jesu Kristi Olugbala wa;
14 Ẹniti o fi ara rẹ̀ fun wa, ki on ki o le
rà wa pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ gbogbo, ati ki o
si sọ enia ọ̀tọ di funfun fun ara rẹ̀, onitara
iṣẹ rere.
15 Nkan wọnyi ni ki iwọ ki o mã sọ, ki
o si ma gbàni niyanju, ki o si mã fi ọlá gbo-
gbo baniwi. Máṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o gàn ọ.

## ORI 3.

MA rán wọn leti lati foribalẹ fun awọn
ijoye ati fun awọn agbara, lati gbà
wọn gbọ́, ati lati mura si iṣẹ rere gbogbo.
2 Li aisọ̀rọ ibi si ẹnikẹni, li aiṣe alaroye,
bikoṣe pẹlẹ, lati mã fi gbogbo ìwa tutù hàn
fun gbogbo enia.
3 Nitoripe awa tikarawa pẹlu nigba mi-
ran ama ṣiwère, alaigbọran, ẹnititàn, ti
nsìn onirũru ifẹkufẹ ati afẹ́, awa mbẹ ninu
arankàn ati ilara, a kún fun irira, a si
nkorira ọmọnikeji ẹni.
4 Ṣugbọn lẹhin ti iṣeun ati ifẹ Ọlọrun
Olugbala wa hàn si enia,
5 Kì iṣe nipa iṣẹ ododo ti awa ti ṣe,
bikoṣe nipa ãnu rẹ̀ o gbà wa là, nipa
ìwẹnu atúnbi, ati isọdi titun Ẹmí Mimọ́;
6 Ti o dà si wa li ọ̀pọlọpọ nipasẹ Jesu
Kristi Olugbala wa;
7 Nipe bi a ti ndá wa lare nipa ore-ọfẹ
rẹ̀, ki a le sọ wa di ajogún gẹgẹ bi ireti ìye
ainipẹkun.
8 Eyiyi li ọ̀rọ otitọ, ati nkan wọnyi li
emi fẹ ki iwọ ki o tẹnumọ nigbakugba, ki
awọn ti o gbà Ọlọrun gbọ́ ki o le mã mura
lati dì iṣẹ rere mu. Nkan wọnyi li o dara
o si ṣe anfani fun enia.
9 Ṣugbọn yẹ̀ kuro ni ìbere wère, ati ìtan,
ati iyàn, ati ìja nipa ti ofin; nitoripe alai-
lere ati asan ni nwọn.
10 Ọkọnrin na ti o ba ṣe aladamọ̀ lẹhin
ìkilọ ikini ati ekeji, kọ̀ ọ;
11 Mã mọ̀ pe irú enia bẹ̃ o yipo, o si ṣẹ̀,
o dá ara rẹ̀ lẹbi.
12 Nigbati emi o ba rán Artema si ọ,
tabi Tikiku, ìàkaka lati tọ̀ mi wá si Niko-
poli: nitori mo ti pinnu rẹ̀ lati potutú
nibẹ̀.
13 Mu Sena amofin ati Apollo wá li ọ̀na
àjo wọn li aisimi, ki ohun kan ki o má ṣe
aini fun wọn.
14 Ki awọn ará wa pẹlu ki o kọ́ bi ãti dì
iṣẹ rere mu nitori ìlo ti o yẹ, ki nwọn ki o
má ba jẹ alaileso.
15 Gbogbo awọn ti mbẹ lọdọ mi kí ọ.
Kí awọn ti o fẹ wa ninu igbagbọ́. Ki ore-
ọfẹ ki o wà pẹlu gbogbo nyin. Amin.

---

A kọ ọ si Titu ti àteteko fi jẹ biṣopu ijọ ni Krete, lati Nikopoli ti Makedonia wá.

---

EPISTELI TI PAULU APOSTELI

SI

# FILEMONI.

PAULU, ondè Jesu Kristi, ati Timoteu
arakọnrin wa, si Filemoni olufẹ ati
alabaṣiṣẹ wa ọwọn,
2 Ati si Affia olufẹ wa, ati si Arkippu
ologun ẹgbẹ wa, ati si ijọ inu ile rẹ:
3 Ore-ọfẹ, ati alafia si nyin, lati ọdọ
Ọlọrun Baba wa, ati Jesu Kristi Oluwa
wa.
4 Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun mi, emi ama ṣe
iranti rẹ nigbagbogbo ninu adura mi,
5 Bi mo ti ngbọ́ ti ifẹ ati igbagbọ́ rẹ, ti
iwọ ni si Jesu Oluwa, ati si gbogbo awọn
enia mimọ́;

Digitized by Google

6 Ki abapin igbagbọ́ rẹ ki o le di arànṣe,
nipa ijẹwọ ohun rere gbogbo ti mbẹ ninu
nyin, nipa Jesu Kristi.
7 Awa sá ni ayọ̀ ati itunu pọ̀ nipa ifẹ
tirẹ, nitoriti a tù awọn enia mimọ ninu lati
ọwọ́ rẹ wá, arakọnrin,
8 Nitorina, bi emi iba tilẹ ti le ṣe igbọ́ju
pupọ̀ nipa Kristi lati paṣẹ ohun ti o yẹ
fun ọ,
9 Ṣugbọn nitori ifẹ emi kuku bẹ̀bẹ, emi
ti iṣe irú enia bi eyi Paulu arugbo, ati ni-
sisiyi pẹlu ondè Jesu Kristi.
10 Emi bẹ̀ ọ nitori Onesimu ọmọ mi,
ẹniti mo bí ninu ìde mi:
11 Nigba atijọ ri, ẹniti iṣe alailere fun
ọ, ṣugbọn nisisiyi o di elere fun ọ ati fun
mi:
12 Ẹniti mo si tún rán pada: nitorina
iwọ gbà a, eyini ni, ọmọ inu mi:
13 Ẹniti emi iba daduro ki o pẹlu mi,
nitoripe ni ipò rẹ ki o le mã ṣe iranṣẹ fun
mi ninu ìde ihin-rere:
14 Ṣugbọn li aimọ̀ inu rẹ emi kò fẹ ṣe
ohun kan; ki ore rẹ ki o má ba dabi afi-
yanjuṣe, bikoṣe tifẹtifẹ.
15 Njẹ bọya nitori eyi li o ṣe lọ kuro
lọdọ rẹ nigba diẹ, ki iwọ ki o le gbà a sọdọ
lailai;
16 Nisisiyi kì iṣe bi ẹrú mọ́, bikoṣe jù
ẹrú lọ, ani arakọnrin olufẹ, pẹlupẹlu fun
mi, melomelo si ni fun iwọ, ati ni ti ara,
ati ni ti Oluwa?
17 Nitorina bi iwọ ba kà mi si alabaṣiṣẹ,
gbà a bi emi tikarami.
18 Bi o ba ti ṣẹ̀ ọ li ohunkohun, tabi ti
o jẹ ọ ni gbese-kigbese, kà a si mi lọrùn.
19 Emi Paulu li o fi ọwọ́ ara mi kọ ọ,
emi o san a: ki emi mã sọ fun ọ, bi iwọ
tikararẹ pẹlu ti jẹ mi ni gbese.
20 Bẹ̃ni arakọnrin, jẹ ki emi ki o ni ayọ̀
tirẹ ninu Oluwa: tù mi ninu nipa ti
Oluwa.
21 Bi mo ti ni igbẹkẹle ni igbọràn rẹ li
emi fi kọwe si ọ, nigbati mo ti mọ̀ pe, iwọ
o si ṣe jù bi mo ti wi lọ.
22 Ṣugbọn pẹlu gbogbo rẹ̀, wá ile ìwọ
silẹ dè mi; nitoriti mo gbẹkẹle pe nipa
adura nyin, a o fi mi fun nyin.
23 Epafra kí ọ, ondè ẹgbẹ mi niti Kristi
Jesu;
24 Marku, Aristarku, Dema, Luku,
awọn alabaṣe mi.
25 Ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa ki o wà
pẹlu ẹmí nyin. Amin.

---

A kọ ọ lati Romu lọ si Filemoni, a rán
a lati ọwọ́ Onesimu lọ, ọmọ-ọdọ.

---

EPISTELI TI PAULU APOSTELI

SI

# AWỌN HEBERU.

## ORI 1.

ỌLỌRUN, ẹni, ni igba pupọ̀ ati li onirũru
ìwa, ti o ti ipa awọn woli ba awọn
baba sọ̀rọ nigbãni,
2 Li ọjọ ikẹhin wọnyi o ti ipasẹ Ọmọ rẹ̀
ba wa sọ̀rọ, ẹniti o fi jẹ arole ohun gbogbo,
nipasẹ ẹniti o ti da awọn aiye pẹlu;
3 Ẹniti iṣe imọlẹ ogo rẹ̀, ati jijọ aworan
ara rẹ̀, ti o si n.i ọ̀rọ agbara rẹ̀ di ohun gbo-
gbo mu, nigbati on tikararẹ̀ ti wẹ̀ ẹ̀ṣẹ wa
nù, o joko li ọwọ́ ọtún Ọlánla li oke;
4 Niti o fi bẹ̃ sànju awọn angeli lọ, nipa
ijogún bi o si ti ni orukọ titayọ jù wọn lọ.
5 Nitoripe awọn angeli wo li o wi ni-
gbakan fun pe, Iwọ li Ọmọ mi, loni ni mo
bí ọ? Ati pẹlu, Emi ni yio ma ṣe Baba
rẹ̀, on ni yio si ma ṣe Ọmọ mi?
6 Ati pẹlu, nigbati o mu akọbi nì wá si
aiye, o ni, Ki gbogbo angeli Ọlọrun ki o si
ma foribalẹ fun u.
7 Ati niti awọn angeli, o wipe, Ẹniti o
dá awọn angeli rẹ̀ li ẹmí, ati awọn iranṣẹ
rẹ̀ li ọwọ́ iná.
8 Ṣugbọn fun Ọmọ li o wipe, Itẹ rẹ,

Digitized by Google

Ọlọrun, lai ati lailai ni; ọpá alade ododo
li ọpá alade ijọba rẹ.
9 Iwọ fẹ ododo, iwọ si korira ẹ̀ṣẹ; nitorina Ọlọrun, ani Ọlọrun rẹ, li o ti ta oróro
ayọ̀ si ọ lori jù awọn ẹgbẹ rẹ lọ.
10 Ati Iwọ, Oluwa, lati ipilẹṣẹ li o ti fi
ipilẹ aiye sọlẹ; awọn ọrun si ni iṣẹ ọwọ́
rẹ:
11 Nwọn o parun; ṣugbọn iwọ duro,
gbogbo wọn ni yio si di gbigbó bi aṣọ;
12 Ati bi agbáda ni iwọ o si ká wọn, a o
si pàrọ wọn: ṣugbọn bakanna ni iwọ, ọdún
rẹ kì yio si pin.
13 Ṣugbọn awọn angeli wo li o wi nigba
kan fun pe, Joko li ọwọ́ ọtún mi, titi emi
o fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti itisẹ rẹ?
14 Ẹmí iranṣẹ ki gbogbo wọn iṣe, ti a
rán lọ lati ṣe iranṣẹ fun awọn ajogún
igbala?

## ORI 2.

NITORINA o yẹ ti awa iba mã fi iye
gidigidi si ohun wọnni ti awa ti gbọ́,
ki awa má jẹ ki nwọn ki o jọ̀ nigbakan.
2 Nitoripe bi ọ̀rọ ti a ba ti ipasẹ awọn
angeli sọ ba duro, ati ti olukuluku arufin
ati aigbọran ngbà ère ẹsan ti o tọ́;
3 Awa o ti ṣe là a, bi awa ba ṣe igbagbé
irú igbala nla bi eyi; ti àteteko bẹ̀rẹ si isọ
lati ọdọ Oluwa, ti a si tẹnumọ fun wa lati
ọdọ awọn ẹniti o gbọ́;
4 Ọlọrun si nfi iṣẹ àmi ati iṣẹ iyanu, ati
onirũru agbara, ati ẹbun Ẹmí Mimọ́ jẹ wọn
li ẹrí, gẹgẹ bi ifẹ rẹ̀?
5 Nitoripe fun awọn angeli ni kò fi aiye
ti mbọ̀ sabẹ wọn, eyiti awa nwi.
6 Ṣugbọn ẹnikan o sọ nibikan pe, Kili
enia, ti iwọ nfiyesi i, tabi ọmọ enia, ti iwọ
mbẹ̀ ẹ wò?
7 Iwọ dá a rẹ̀lẹ diẹ jù awọn angeli lọ;
iwọ fi ogo ati ọlá dé e li ade, iwọ si fi i jẹ
olori iṣẹ ọwọ́ rẹ:
8 Iwọ ti tẹ̀ ori ohun gbogbo ba sabẹ ẹsẹ
rẹ̀. Nitori niti o tẹ̀ ori ohun gbogbo ba
sabẹ rẹ̀, kò kù ohun kan ti a kò fi sabẹ rẹ̀.
Ṣugbọn nisisiyi awa kò ti iri ki a tẹ̀ ori
ohun gbogbo ba sabẹ rẹ̀.
9 Ṣugbọn awa ri Jesu, ẹniti a dá rẹ̀lẹ diẹ
jù awọn angeli lọ nitori ìjiya ikú, a fi ogo
ati ọlá dé e li ade; pe nipa ore-ọfẹ Ọlọrun
ki o le tọ́ ikú wò fun enia gbogbo.
10 Nitoripe o yẹ fun u, ẹniti ohun gbogbo wà fun, ati nipasẹ ẹniti ohun gbogbo
wà, ni mimu awọn ọmọ pupọ̀ wá sinu ogo,
lati ṣe balogun igbala wọn li aṣepé nipa
ìjiya.
11 Nitoripe ẹniti nsọni di mimọ́ ati awọn
ti a nsọ di mimọ́ ti inu ọkan ni gbogbo
wọn: nitori na ni kò ṣe tiju lati pè wọn
ni ará,
12 Wipe, Emi o sọ̀rọ orukọ rẹ fun awọn
ará mi, li arin ijọ li emi o kọrin iyìn si ọ.
13 Ati pẹlu, Emi o gbé ẹ̀kẹ mi le e.
Ati pẹlu, Kiyesi i, emi ati awọn ọmọ ti
Ọlọrun fifun mi.
14 Njẹ niwọn bi awọn ọmọ ti ṣe alabapin
ara on ẹ̀jẹ, on tikararẹ̀ pẹlu si mu ipa ninu
rẹ̀ na; pe nipa ikú ki o le pa ẹniti o ni
agbara ikú run, eyini ni Eṣu;
15 O si yọ awọn, nipa ìbẹru ikú, ti mbẹ
labẹ ìde li ọjọ aiye wọn gbogbo.
16 Nitoripe nitõtọ kò gbà ẹda angeli;
ṣugbọn o gbà ẹda irú-ọmọ Abrahamu.
17 Nitorina ninu ohun gbogbo o yẹ fun
u ki a dá a bi awọn ará rẹ̀, ki o le jẹ olori
alufa alãnu ati olõtọ ninu ohun ti iṣe ti
Ọlọrun, lati ṣe ìlaja nitori ẹ̀ṣẹ awọn enia.
18 Nitori ninu eyi ti on tikararẹ̀ ti jìya,
ti a ti dán a wò, o si le ràn awọn ti a
ndánwò lọwọ.

## ORI 3.

NITORINA ẹnyin ará mimọ́, alabapin
ìpe ọrun, ẹ gbà Jesu Kristi rò, Aposteli ati Olori Alufa ijẹwọ wa;
2 Ẹniti o ṣe olõtọ si ẹniti o yàn a, bi
Mose pẹlu ti ṣe ninu ile rẹ̀ gbogbo.
3 Nitoripe a kà ọkọnrin yi ni yiyẹ si
ogo jù Mose lọ, niwọn bi ẹniti o kọ́ ile ti li
ọla jù ile na lọ.
4 Lati ọwọ́ enia kan li a sá ti kọ́ olukuluku ile; ṣugbọn ẹniti o kọ́ ohun gbogbo
ni Ọlọrun.
5 Nitõtọ ni Mose ṣe olõtọ ninu ile rẹ̀
gbogbo, bi iranṣẹ, fun ẹrí ohun wọnni ti a
o ma sọ̀rọ rẹ̀ nigba ikẹhin;
6 Ṣugbọn Kristi bi ọmọ lori ile ara rẹ̀;
ile ẹniti awa iṣe, bi awa ba dì igbẹkẹle ati
ayọ̀ ireti wa mu ṣinṣin titi de opin.
7 Nitorina bi Ẹmí Mimọ́ ti wi pe, Loni
nigbati ẹnyin o gbọ́ ohùn rẹ̀,
8 Ẹ máṣe sé àiya nyin le, bi igba imunibinu, li ọjọ idanwò li aginjù:
9 Nigbati awọn baba nyin dán mi wò,
ti nwọn mọ̀ mi, ti nwọn si ri iṣẹ mi li ogoji
ọdún.
10 Nitorina inu mi bajẹ si iran na, mo
si wipe, Nigbagbogbo ni nwọn nṣìna li
àiya wọn; nwọn kò si mọ̀ ipa ọ̀na mi.
11 Bẹ̃ni mo si bura ni ibinu mi pe, Bi
nwọn o ti wọ̀ ibi isimi mi.
12 Ẹ mã ṣọra, ará, ki àiya buburu ti



Digitized by Google

aigbagbọ́ ki o máṣe wà ninu ẹnikẹni nyin, ni ilọ kuro lọdọ Ọlọrun alãye.
13 Ṣugbọn ẹ mã gbà ara nyin niyanju li ojojumọ́, nigbati a npè Loni; ki ẹnikẹni ninu nyin ki o má ba sé àiya le nipa ẹ̀tan ẹ̀ṣẹ.
14 Nitori a sọ wa di alabapin pẹlu Kristi, bi awa bi dì ipilẹṣẹ igbẹkẹle wa mu ṣinṣin titi de opin;
15 Nigbati a nwipe, Loni nigbati ẹnyin o gbọ́ ohùn rẹ̀, ẹ máṣe sé àiya nyin le, bi igba imunibinu.
16 Nitoripe awọn ẹlomiran, nigbati nwọn gbọ́ tan, nwọn ṣe imunibinu: ṣugbọn kì iṣe gbogbo awọn ti o ti ipasẹ Mose ti Egipti jade wá.
17 Ṣugbọn awọn wo ni inu rẹ̀ bajẹ si li ogoji ọdún? koṣepe si awọn ti o ti ṣẹ̀ ni, okú awọn ẹniti o sun li aginjù?
18 Awọn tali o si bura fun pe nwọn kì yio wọ̀ ibi isimi rẹ̀, bikoṣe fun awọn ti kò gbagbọ́?
19 Bẹ̃li awa ri pe nwọn kò le wọ̀ inu rẹ̀ nitori aigbagbọ́.

## ORI 4.

NITORINA ki awa ki o bẹ̀ru, nitoripe, bi a ti fi ileri silẹ fun wa lati wọ̀ inu isimi rẹ̀, ki ẹnikẹni ninu nyin ki o máṣe dabi ẹnipe yio kùna si i.
2 Nitoripe awa li a wasu ihin-rere fun, gẹgẹ bi fun wọn: ṣugbọn ọ̀rọ ti a wasu fun wọn kò gbè fun wọn, nitori ti kò dàpọ pẹlu igbagbọ́ ninu awọn ti o gbọ́ ọ.
3 Nitoripe awa ti o ti gbagbọ́ nwọ̀ inu isimi, bi o ti wipe, Gẹgẹ bi emi ti bura ninu ibinu mi pe, Bi nwọn o ti wọ̀ ibi isimi mi: bi o tilẹ ti ṣe pe iṣẹ wọnni ti pari lati ipilẹ aiye.
4 Nitori o ti sọ nibikan bayi niti ọjọ keje pe, Ọlọrun ti simi ni ijọ keje lọwọ iṣẹ rẹ̀ gbogbo.
5 Ati nihinyi ẹ̀wẹ pe, Bi nwọn o ti wọ̀ ibi isimi mi.
6 Nitorina bi ti o jẹ pe, o kù pe awọn ẹlomiran yio wọ̀ inu rẹ̀, ati awọn ti a tète wasu fun, kò wọ̀ inu rẹ̀ nitori aigbagbọ́:
7 Ati pẹlu, o pinnu ọjọ kan, o nwi ninu Iwe Dafidi pe, Loni, lẹhin ìgba pipẹ bẹ̃; bi a ti wipe, Loni, nigbati ẹnyin o gbọ́ ohùn rẹ̀, ẹ máṣe sé àiya nyin le.
8 Nitoripe ibaṣepe Joṣua ti fun wọn ni isimi, njẹ on kì ba ti sọ lẹhinna ti ọjọ miran.
9 Nitorina isimi kan kù fun awọn enia Ọlọrun.
10 Nitoripe ẹniti o ba bọ́ sinu isimi rẹ̀, on pẹlu ṣiwọ kuro ninu iṣẹ tirẹ̀, gẹgẹ bi Ọlọrun ti ṣe kuro ni tirẹ̀.
11 Nitorina ẹ jẹ ki a ṣe lãlã lati wọ̀ inu isimi na, ki ẹnikẹni ki o má ba ṣubu nipa ifarawe aigbagbọ́.
12 Nitoripe ọ̀rọ Ọlọrun yè, o si li agbara, o si mú jù idà oloju meji lọ, o ngún-ni ani lati pín ọkàn ati ẹmí yà si ọ̀tọ, ati orike egungun ati ọrá egungun, on si ni olumọ̀ ironu ati ete àiya.
13 Bẹ̃ni kò si ẹda kan ti kò hàn li oju rẹ̀: ṣugbọn ohun gbogbo li o ṣe ìhoho ti o si ṣí silẹ si oju rẹ̀ ẹniti awa ni ba ṣe.
14 Njẹ bi awa ti ni Olori Alufa nla kan, ti o ti kọja lọ sinu awọn ọrun, Jesu Ọmọ Ọlọrun, ẹ jẹ ki a dì ijẹwọ wa mu ṣinṣin.
15 Nitoripe awa kò ni olori alufa kan, ti o ṣe alaimọ̀ ẹ̀dun ailera wa; ṣugbọn ẹni ninu ori ohun gbogbo li a dán a wò gẹgẹ bi awa, ṣugbọn li ailẹṣẹ.
16 Nitorina ẹ jẹ ki a fi igboiya wá si ibi itẹ́ ore-ọfẹ, ki a le ri ãnu gbà, ki a si ri ore-ọfẹ lati mã ràn-ni lọwọ ni igba ipọnju.

## ORI 5.

NITORI olukuluku olori alufa ti a yàn ninu awọn enia, li a fi jẹ fun awọn enia niti ohun ti iṣe ti Ọlọrun, ki o le mã ta ọrẹ ẹ̀bun on ati ṣe ẹbọ nitori ẹ̀ṣẹ:
2 Ẹniti o le ṣãnu fun awọn òpe, ati fun awọn ti o ti yà kuro loju ọ̀na; nitoripe ailera yí on na ká pẹlu.
3 Nitori idi eyi li o si ṣe yẹ, bi o ti nṣe fun awọn enia, bẹ̃ni pẹlu ki o ṣe ẹbọ nitori ẹ̀ṣẹ fun ara rẹ̀.
4 Kò si si ẹniti o gbà ọlá yi fun ara rẹ̀, bikoṣe ẹniti a pè lati ọdọ Ọlọrun wá, gẹgẹ bi Aaroni.
5 Bẹ̃ni pẹlu Kristi kò si yìn ara rẹ̀ logo lati fi on jẹ olori alufa; bikoṣe ẹniti o wi fun u pe, Iwọ li Ọmọ mi, loni ni mo bí ọ.
6 Bi on ti wi pẹlu nibomiran pe, Iwọ ni alufa titi lai nipa ẹsẹ Melkisedeki.
7 Ẹni nigba ọjọ ara rẹ̀, nigbati o fi ẹkún rara ati omije gbadura, ti o si bẹ̀bẹ lọdọ ẹniti o le gbà a silẹ lọwọ ikú, a si gbọ́ ọ ninu eyi ti o ṣe ìbẹru;
8 Bi o tilẹ ti ṣe Ọmọ, ṣugbọn o kọ́ igbọran nipa ohun ti o jìya;
9 Bi a si ti sọ di pipé, o wá di olupilẹṣẹ igbala ainipẹkun fun gbogbo awọn ti o gbà a gbọ́:
10 Ti a pè li olori alufa lati ọdọ Ọlọrun wá nipa ẹsẹ Melkisedeki.
11 Niti ẹniti awa ni ohun pupọ̀ lati wi,

Digitized by Google

ti o si ṣoro lati sọ, nitori pe ẹ yigbì ni
gbigbọ́.
12 Nitori nigbati akokò ti o yẹ ti ẹnyin
iba mã ṣe olukọ, ẹ si wà li ẹniti ẹnikan yio
si mã tun kọ́ ni ohun ti o tète ṣe ipilẹṣẹ
ọ̀rọ ijinlẹ Ọlọrun; ẹ si wá dabi irú awọn ti
kò le ṣe aini wàra, ti kì iṣe onjẹ lile.
13 Nitoripe gbogbo ẹniti nlò wàra o ṣe
alaigbó ninu ọ̀rọ ododo: nitoripe ọmọ ọwọ
ni.
14 Ṣugbọn onjẹ lile ni fun awọn ti o ni
ọjọ kikun lori, awọn ẹni nipa ìlo, ti nwọn
nlò ọgbọ́n wọn lati mọ̀ rere ati buburu.

## ORI 6.

NITORINA ki a fi ipilẹṣẹ ẹkọ́ Kristi silẹ,
ki a lọ si pipé; li aitún fi ipilẹ ironu-
piwada kuro ninu okú iṣẹ lelẹ, ati ti igba-
gbọ́ sipa ti Ọlọrun,
2 Ti ẹkọ́ ti baptismu, ati ti ifọwọleni,
ati ti ajinde okú, ati ti idajọ ainipẹkun.
3 Eyi li awa o si ṣe, bi Ọlọrun fẹ.
4 Nitori niti awọn ti a ti ṣí loju lẹ̃kan,
ti nwọn si ti tọ́ ẹbun ọrun wò, ti a si fi ṣe
alabapin Ẹmí Mimọ́,
5 Ti nwọn si ti tọ́ ọ̀rọ rere Ọlọrun wò,
ati agbara aiye ti mbọ̀wa,
6 Bi nwọn ba yipada kuro, o ṣoro lati
tún mu wọn pada nititun si ironupiwada;
nwọn sa ti kàn Ọmọ Ọlọrun mọ agbelebu
si ara wọn li ọtun, nwọn si dojutì i ni-
gbangba.
7 Nitoripe ilẹ ti nmu omi òjo ti nrọ̀ si i
lori nigbakugba, ti o si nhù ewebẹ ti o yẹ
fun awọn, nipa ọwọ́ ẹniti a nṣe itọju rẹ̀, o
gbà ibukún lọwọ Ọlọrun:
8 Ṣugbọn eyiti o nso ẹgún ọ̀gan ati oṣu-
ṣu, a kọ̀ ọ, kò si jìna si egún; opin ẹniti a
o fi jóna.
9 Ṣugbọn, olufẹ, a nrò nkan ti o darajù
bẹ̃ lọ si nyin, ati ohun ti ibá igbala rìn pọ̀,
bi awa tilẹ nsọ bẹ̃.
10 Nitoripe Ọlọrun kì iṣe alaiṣododo
lati gbagbé iṣẹ ati lãlã ifẹ nyin, ti ẹnyin ti
fihàn sipa orukọ rẹ̀, niti ẹnyin ti nṣe iranṣẹ
fun awọn enia mimọ́, ẹ si ti nṣe e sibẹ̀.
11 Awa si fẹ ki olukuluku nyin ki o mã
fi irú aisimi bẹ̃ hàn, de kíkun idanilojú
ireti titi de opin:
12 Ki ẹnyin ki o máṣe ilọra, bikoṣe ọmọ
lẹhin awọn ẹni, nipa igbagbọ́ ati sũru, ti
jogún ileri wọnni.
13 Nitori nigbati Ọlọrun ṣe ileri fun
Abrahamu, nitoriti kò le ri ẹniti o jù u fi
bura, o fi ara rẹ̀ bura,
14 Wipe, Nitõtọ, ni bibukún emi o
bukún u fun ọ, ati ni bibisi emi o mu ọ
bisi i.
15 Bẹ̃ si ni, lẹhin igbati o fi sũru forití
i, o ri ileri na gbà.
16 Nitõtọ sá ni enia ama fi ẹniti o jù u
bura: ati èpe ifidi ọ̀rọ mulẹ on ni opin ìja
gbogbo fun wọn.
17 Ninu eyiti Ọlọrun, nfẹ gidigidi lati
fihàn si i fun awọn ajogún ileri, aiyipada
ìmọ rẹ̀, o fi ibura sãrin.
18 Pe nipa ohun aiyipada meji, ni ti
o ṣoro fun Ọlọrun lati ṣeke, ki awa ti o sá
si àbo, ki a le ni itunu ti o lẹṣẹ nilẹ, lati dì
ireti nì mu ti a gbé kalẹ niwaju wa:
19 Ireti na ti a ni bi ohun idakọ̀ro ọkàn,
ti o daniloju, ti o si duro ṣinṣin, eyiti o si
wọ̀ inu ikele aṣọ lọ;
20 Nibiti aṣaju wa ti wọ̀ lọ fun wa, ani
Jesu, ti a fi jẹ olori alufa titi lai nipa ẹsẹ
Melkisedeki.

## ORI 7.

NITORI Melkisedeki yi, ọba Salemu,
alufa Ọlọrun ọgá-ogo, ẹniti o pade
Abrahamu ti npada lati ibi pipa awọn ọba
wọnni bọ̀, ti o si sure fun u;
2 Ẹniti Abrahamu si fi ida-mẹwa ohun
gbogbo fun; nipa àtete tumọ̀, on ni ọba
ododo ati lẹhinna pẹlu ọba Salemu, ti iṣe
ọba alafia;
3 Laini baba, laini iyá, laini ipilẹ ìtan,
bẹ̃ni kò ni ipilẹṣẹ ọjọ, tabi opin ìwa; bi-
koṣe pe bi a ti dá a bi Ọmọ Ọlọrun; o wà
li alufa titi aiye.
4 Ṣugbọn ẹ gbà a rò bi ọkọnrin yi ti pọ̀
to, ẹniti Abrahamu baba-nla dá ida-mẹwa
ikogun wọnni fun.
5 Ati nitõtọ awọn ti iṣe ọmọ Lefi, ti o
gbà oyè alufa, nwọn ni aṣẹ lati mã gbà ida-
mẹwa lọwọ awọn enia gẹgẹ bi ofin, eyini ni,
lọwọ awọn arakọnrin wọn, bi a tilẹ mọ̀ pe,
nwọn ti inu Abrahamu jade wá:
6 Ṣugbọn on ẹniti a kò kà ipilẹ ìtan rẹ̀
lati ọdọ wọn wá, o gbà ida-mẹwa lọwọ
Abrahamu, o si sure fun ẹniti o gbà ileri.
7 Ati li aijiyàn kan, ọmọ-ẹhin li ã sure
fun lati ọdọ àgba wá.
8 Ati nihinyi awọn enia ti nkú gbà ida-
mẹwa; ṣugbọn nibẹ̀, ẹnikan ẹniti a jẹri fun
pe o mbẹ lãye.
9 Bi emi iba si ti wi pe, Lefi pẹlu, ti
ngbà ida-mẹwa, o san ida-mẹwa ninu
Abrahamu.
10 Nitori o sá mbẹ ni inu baba rẹ̀ Abra-
hamu, nigbati Melkisedeki pade rẹ̀.
11 Njẹ ibaṣepe pipé mbẹ ni oyè alufa

Digitized by Google

Lefi, (nitoripe labẹ rẹ̀ li awọn enia gbà ofin,)
kili o si tún kù mọ́ ti oyè alufa miran yio
hù nipa ẹsẹ Melkisedeki, ti a kò si pè e
nipa ẹsẹ Aaroni?
12 Nitoripe bi a ti pàrọ oyè alufa, a kò
si le ṣe aima pàrọ ofin pẹlu.
13 Nitoripe ẹniti a nsọ̀rọ nkan wọnyi si,
ti ara ẹ̀ya miran ni, ninu eyiti kò si ẹniti
iduro ti pẹpẹ.
14 Nitori o daniloju pe, lati ẹ̀ya Juda ni
Oluwa wa ti jade wá; ninu ẹ̀ya na ti Mose
kò sọ̀rọ kan nipa ti oyè alufa.
15 O si tún daniloju si i jù bẹ̃ pe: ni-
toripe nipa ẹsẹ apẹrẹ Melkisedeki, alufa
omiran hù,
16 Ẹniti a fi jẹ, kì iṣe nipa aṣẹ ofin ti
ara, bikoṣe nipa agbara ti ìye ailopin.
17 Nitori o jẹri pe, Iwọ ni alufa kan titi
lai nipa ẹsẹ Melkisedeki.
18 Nitori imukuro ofin atijọ mbẹ nibẹ̀,
nitori ailera ati ailere rẹ̀.
19 Nitoripe ofin kò le mu ohunkohun
pé, ṣugbọn imu ireti ti o darajù a mã ṣe e;
nipa eyi ti awa nsunmọ Ọlọrun.
20 Ati bi o si ti ṣe pe kì iṣe li aibura li
a fi jẹ alufa:
21 (Nitoripe a fi awọn alufa wọnni jẹ li
aibura; ṣugbọn eyi ni ibura lati ọwọ́ ẹniti
o wi fun u pe, Oluwa bura, kì yio si ronu-
piwada, Iwọ ni alufa kan titi lai nipa ẹsẹ
Melkisedeki:)
22 Niwọn tobẹ̃ li a fi Jesu jẹ onigbọwọ
majẹmu ti o darajù.
23 Ati nitõtọ alufa pupọ̀ ni nwọn iṣe,
nitori ti nwọn kò le wà titi nitori ikú:
24 Ṣugbọn ọkọnrin yi, nitoriti o duro
titi lai, o ni oyè alufa ti a kì iró nipò.
25 Nitorinà o si le gbà wọn là pẹlu titi
de opin, ẹniti o ba tọ̀ Ọlọrun wá nipasẹ rẹ̀,
nitori ti o mbẹ lãye titi lai lati mã bẹ̀bẹ
fun wọn.
26 Nitoripe irú olori alufa bẹ̃ li o yẹ wa,
mimọ́, ailewu, ailẽri, ti a yà si ọ̀tọ kuro
ninu ẹlẹṣẹ, ti a si gbéga jù awọn oke ọrun
lọ;
27 Ẹniti kò ni iṣe li ojojumọ́, bi awọn
olori alufa wọnni, lati tète ṣe ẹbọ nitori
ẹ̀ṣẹ ti ara rẹ̀ na, ki o to ṣe nitori ti awọn
enia: nitoripe eyi li o ti ṣe lẹ̃kan, nigbati
o fi ara rẹ̀ rubọ.
28 Nitoripe ofin ama fi awọn enia ti o ni
ailera jẹ olori alufa; ṣugbọn ọ̀rọ ti ibura, ti
o hù lẹhin ofin, o fi Ọmọ jẹ, ẹniti a sọ di
pipé titi lai.

## ORI 8.

ṢUGBỌN ipari ohun wọnni ti a ti nsọ li
eyi: Awa ni irú olori alufa kan, ti o
joko li ọwọ́ ọtún itẹ́ ọlánla julọ li ọrun:
2 Alufa ti ibi mimọ́ ati ti agọ́ tõtọ, ti
Oluwa pa kì iṣe enia,
3 Nitoripe a fi olukuluku olori alufa jẹ
lati mã ta ọrẹ ẹ̀bun on ati ṣe ẹbọ: nitorina
ọkọnrin yi kò le ṣe alaini ohun ti yio fi
rubọ pẹlu.
4 Nitori ibaṣepe o mbẹ li aiye, on kì ba
ti jẹ alufa, nitori ti awọn alufa mbẹ ti nta
ọrẹ ẹ̀bun gẹgẹ bi ofin:
5 Awọn ẹniti nsìn bi apẹrẹ ati ojiji nkan
ọrun wọnni, bi ati kọ́ Mose lati ọdọ Ọlọrun
wá nigbati o mura ati pa agọ́: o wi pe, sá
wò o, ki iwọ ki o ṣe ohun gbogbo gẹgẹ bi
apẹrẹ ti a fihàn ọ lori òke.
6 Ṣugbọn nisisiyi li o ni oyè alufa ti o li
ọlá jù bẹ̃ lọ, nipa melo pẹlu li o ṣe ala-
gbawi majẹmu ti o darajù, ti a fi idi rẹ̀ lelẹ
lori ileri ti o sàn jù bẹ̃ lọ.
7 Nitori ibaṣepe majẹmu iṣaju na kò ni
àbuku, njẹ a kì ba ti wá àye fun ekeji.
8 Nitoriti o ri àbukun lara wọn, o wipe,
Kiyesi i, ọjọ mbọ̀, li Oluwa wi, nigbati emi
o bá ara ile Israeli da majẹmu titun ati
pẹlu ile Juda.
9 Kì iṣe bi majẹmu ti mo ti bá awọn
baba wọn dá, li ọjọ na ti mo fà wọn lọwọ
lati sìn wọn jade kuro ni ilẹ Egipti; ni-
toriti nwọn kò duro ninu majẹmu mi, emi
kò si kà wọn si, ni Oluwa wi.
10 Nitori eyi ni majẹmu ti emi o ba
ará ile Israeli da lẹhin ọjọ wọnni, Oluwa
wipe; Emi o fi ofin mi si wọn ni inu, emi
o si kọ wọn si àiya wọn: emi o si mã jẹ
Ọlọrun fun wọn, nwọn o si mã jẹ enia fun mi:
11 Nwọn kì yio si mã kọ́ni olukuluku
aladugbo rẹ̀, tabi olukuluku arakọnrin rẹ̀,
wipe, Mọ̀ Oluwa: nitoripe gbogbo wọn
ni yio mọ̀ mi, lati kekere de àgba.
12 Nitoripe emi o ṣãnu fun aiṣododo
wọn, ati ẹ̀ṣẹ wọn ati aiṣedede wọn li emi kì
yio si ranti mọ́.
13 Li eyi ti o wipe, Majẹmu titun, o ti
sọ ti iṣaju di ṣiṣá. Ṣugbọn eyi ti o ṣá, ti o
si gbó, o mura ati di asan.

## ORI 9.

NJẸ nitõtọ majẹmu ti iṣaju pẹlu ni ìlana
ìsin Ọlọrun, ati ibi mimọ́ ti aiye.
2 Nitoripe a pa agọ́ kan; eyi ti iṣaju, ti
a npè ni ibi mimọ́, ninu eyi ti ọpá fitila gbé
wà, ati tabili, ati akara ifihàn.

Digitized by Google

3 Ati lẹhin aṣọ ikele keji, on ni agọ́ ti a npè ni Ibi Mimọ́ jùlọ ;
4 Ti o ni tasa wura ti turari, ati apoti majẹmu ti a fi wura tẹ́ yiká kiri, ninu eyi ti ikoko wura manna gbé wà, ati ọpá Aaroni ti o rudi, ati awọn tabili majẹmu nì ;
5 Ati lori rẹ̀ ni awọn kerubu ogo ti o ṣijibo ibujoko ãnu ; eyi ti a kò le fi ẹnu sọ ṣãn nisisiyi.
6 Njẹ nigbati a làna nkan wọnyi bẽ, awọn alufa ama lọ nigbakugba sinu agọ́ iṣaju àtetekàn, nwọn ama lọ sìn ìsin Ọlọrun.
7 Ṣugbọn sinu ekeji ni olori alufa nikanṣoṣo ima lọ lẽkan li ọdún, kì iṣe li aini ẹ̀jẹ, ti on fi rubọ fun ara rẹ̀ na, ati fun ìṣina awọn enia :
8 Ẹmí Mimọ́ nfi eyi ṣapẹrẹ, pe ọ̀na sinu Ibi Mimọ́ kò ti ihàn, nigbati agọ́ iṣaju ba mbẹ ni iduro :
9 Eyiti iṣe apẹrẹ fun igba na, ninu eyiti a ta ọrẹ ẹ̀bun, ti a si nru ẹbọ, ti kò le mu ẹniti nsìn ìsin na pé, nipa eyiti iṣe ti ọkàn ;
10 Eyiti o duro ni kìki ohun jijẹ ati ohun mimu, ati ni onirũru ìwẹ, ati ìlana ti ara, ti a fi le wọn lori titi yio fi di igba atún-pada-ṣe.
11 Ṣugbọn Kristi ti wá lati ṣe olori alufa ohun rere ti mbọ̀, nipa agọ́ ti o tobi, ti o si péjù, ti a kò fi ọwọ́ pa, eyini ni pe, kì iṣe ti ẹ̀da yi ;
12 Bẽni kì iṣe nipasẹ ẹ̀jẹ ewurẹ ati ọmọ malu, ṣugbọn nipa ẹ̀jẹ on tikararẹ̀ li o fi wọle lẽkanṣoṣo sinu ibi mimọ́ nì, lẹhin ti o ri idande ainipẹkun gbà fun wa.
13 Nitori bi ẹ̀jẹ akọ malu ati ewurẹ, ati ẽru ẹgbọrọ abo malu ti a nta si ara alaimọ́, ba nyàni si mimọ́ si isọ ara di mimọ́ :
14 Melomelo li ẹ̀jẹ Kristi, ẹni nipa Ẹmí titilai ti o fi ara rẹ̀ rubọ si Ọlọrun li aini àbawọn, yio wẹ̀ ọkàn nyin nu mọ́ kuro ninu okú iṣẹ lati sìn Ọlọrun alãye ?
15 Ati nitori eyi li o ṣe di onilaja majẹmu titun, pe nipasẹ ikú, nitori idande irekọja ti o ti mbẹ labẹ majẹmu iṣaju, ki awọn ti a ti pè ki o le ri ileri ijogún ainipẹkun gbà.
16 Nitori nibiti iwe majẹmu gbé wà, ikú oni-majẹmu kò le ṣe aisi pẹlu.
17 Nitori iwe majẹmu li agbara lẹhin igbati enia ba kú tan : bikoṣe bẹ̃ on kò li agbara rara nigbati oni-majẹmu mbẹ lãye.
18 Njẹ nitori eyi na li a kò si ṣe yà majẹmu iṣaju si mimọ́ li aini ẹ̀jẹ.
19 Nitori nigbati Mose ti sọ̀rọ olukuluku ofin fun gbogbo awọn enia gẹgẹ bi ofin, o mu ẹ̀jẹ ọmọ malu ati ti ewurẹ, pẹlu omi, ati owu ododó, ati ewe hissopu, o si fi wọ́n ati iwe ati gbogbo enia,
20 On wipe, Eyiyi li ẹ̀jẹ majẹmu ti Ọlọrun pa laṣẹ fun nyin.
21 Pẹlupẹlu o fi ẹ̀jẹ wọ́n ati agọ́, ati gbogbo ohun-èlo ìsin alufa.
22 O si fẹrẹ iṣe ohun gbogbo nipa ofin li a fi ẹ̀jẹ wẹ̀numọ́ ; ati li aita ẹ̀jẹ silẹ imukuro ẹ̀ṣẹ kò si.
23 Nitorina o yẹ ki a fi wọnyi wẹ̀ nkan ti iṣe apẹrẹ ohun ọrun nù ; ṣugbọn ohun ọrun tikarawọn ki a fi ẹbọ ti a darajù wọnyi lọ wẹ̀ wọn nù.
24 Nitori Kristi kò wọ̀ inu ibi mimọ́ wọnni lọ ti a fi ọwọ́ ṣe, ti iṣe apẹrẹ ti otitọ; ṣugbọn o lọ si ọrun tikararẹ̀, nisisiyi lati wá si iwaju Ọlọrun fun wa :
25 Kì si iṣe pe ki o le mã fi ara rẹ̀ rubọ nigbakugba, bi olori alufa ti ima wọ̀ inu ibi mimọ́ lọ li ọlọdún ti on ti ẹ̀jẹ ẹlomiran;
26 Njẹ nitori bẹ̃ on kò le ṣaima mã jìya nigbakugba lati ìgba ipilẹ ọjọ ìwa : ṣugbọn nisisiyi li o fi ara hàn lẽkan li opin aiye lati mu ẹ̀ṣẹ kuro nipa ẹbọ ara rẹ̀.
27 Bi a si ti pinnu rẹ̀ fun enia pe lẽkan li ã kú, ṣugbọn lẹhin eyi ni idajọ :
28 Bẽli a si fi Kristi rubọ lẽkan lati rù ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ enia ; ati fun awọn ti nwoye ọ̀na rẹ̀ ni on o si farahàn nigba keji lailẹṣẹ si igbala.

## ORI 10.

NITORI ofin ti o ni ojiji ohun rere ti mbọ̀, kì iṣe aworan ti nkan wọnni, pẹlu ẹbọ wọnni ti nwọn nru nigbagbogbo li ọdọdún, kò le mu awọn ti nwá sibẹ̀ di pipé.
2 Njẹ nitorina a kì ba ti dẹkun lati mã ru wọn li ẹbọ ? nitoripe awọn olùsin ti a ti wẹ̀numọ́ lẽkan kì ba ti ni ìmọ ẹ̀ṣẹ mọ́.
3 Ṣugbọn ninu ẹbọ wọnni a si tún nṣe iranti ẹ̀ṣẹ li ọdọdún.
4 Nitori o ṣoro ti ẹ̀jẹ akọ malu ati ti ewurẹ, yio fi mu ẹ̀ṣẹ kuro.
5 Nitorina nigbati o wá si aiye, o wipe, Ẹbọ ati ẹbọ ọrẹ iwọ kò fẹ, ṣugbọn ara ni iwọ ti pèse silẹ fun mi :
6 Ninu ẹbọ ọrẹ sisun ati ẹbọ nitori ẹ̀ṣẹ iwọ kò ni inu-didùn si.
7 Nigbana ni mo wipe, Kiyesi i, Mo dé lati ṣe ifẹ tirẹ, Ọlọrun (ninu àpo iwe nì li a gbé kọ ọ nipa ti emi).
8 Nitiṣaju nigbati o wipe, Ẹbọ, ati ẹbọ ọrẹ, ati ẹbọ ọrẹ sisun, ati ẹbọ nitori ẹ̀ṣẹ ni

Digitized by Google

iwọ kò fẹ, bẹ̃ni iwọ kò ni inùdidùn si i; ti
a nrú nipa ti ofin;
9 Nigbana ni o wipe, Kiyesi i, Mo dé
lati ṣe ifẹ tirẹ, Ọlọrun. O mu ti iṣaju kuro,
ki o le fi idi ekeji mulẹ.
10 Nipa ifẹ yi na li a nsọ wa di mimọ́
nipa ifi ara Jesu Kristi tọrọ lẹ̃kanṣoṣo.
11 Ati olukuluku alufa ti nduro li ojo-
jumọ́ ti nṣe ìsin, ti o si nṣe ẹbọ kanna ni-
gbakugba, ti kò le mu ẹ̀ṣẹ kuro lai:
12 Ṣugbọn ọkọnrin yi, lẹhin igbati o ti
ru ẹbọ kan fun ẹ̀ṣẹ titi lai, o joko li ọwọ́
ọtún Ọlọrun;
13 Lati isisiyi lọ, o nreti titi a o fi fi
awọn ọtá rẹ̀ ṣe apoti itisẹ rẹ̀.
14 Nitori nipa ẹbọ kan o si ti mu awọn
ti a sọdi mimọ́ pé titi lai.
15 Ẹmí Mimọ́ si li ẹlẹri fun wa pẹlu:
nitori lẹhin igbati o ti wi ṣaju pe,
16 Eyi ni majẹmu ti emi o ba wọn dá
lẹhin ọjọ wọnni, Oluwa wipe, emi o fi ofin
mi si wọn li àiya, ati ni inu wọn li emi o
kọ wọn si;
17 Ati awọn ẹ̀ṣẹ wọn ati aiṣedede wọn li
emi kì yio si ranti mọ́.
18 Ṣugbọn nibiti imukuro nkan wọnyi
ba gbé wà, irubọ nitori ẹ̀ṣẹ kò si mọ́.
19 Ará, njẹ bi a ti ni igboiya lati wọ̀
inu ibi mimọ́ julọ nipasẹ ẹ̀jẹ Jesu,
20 Nipa ọ̀na titun ati alãye, ti o ti yà si
mimọ́ fun wa, nipasẹ aṣọ ikele nì, eyini ni
pe, ara rẹ̀;
21 Ati pe ti a ni olori alufa kan lori ile
Ọlọrun;
22 Ẹ jẹ ki a fi otitọ àiya sunmọ tosi pẹlu
idaniloju ti o kún fun igbagbọ́, ki a si fi
ibuwọ́n wẹ̀ ọkàn buburu wa nù, ki a si fi
omi mimọ́ wẹ̀ ara wa nù.
23 Ẹ jẹ ki a dì ijẹwọ ireti wa mu li aiṣi-
yemeji; (nitoripe olõtọ li ẹniti o ṣe ileri;)
24 Ẹ jẹ ki a si gbà a rò lati rú ara wa si
ifẹ ati si iṣẹ rere:
25 Li aikọ̀ ipejọ pọ̀ ara wa silẹ, gẹgẹ bi
ìwa awọn ẹlomiran ti ri; ṣugbọn ki ama
gbà ara ẹni niyanju: tobẹ̃ melomelo si ni,
bi ẹnyin ti ri ti ọjọ nsunmọ etile.
26 Nitori bi awa ba mọ̃mọ̀ dẹṣẹ lẹhin
igbati awa ba ti gbà ìmọ otitọ, ẹbọ nitori
ẹ̀ṣẹ kò si mọ́,
27 Bikoṣe iwoye kan ti o ni ìbẹru idajọ,
ati ti ibinu ti o muná, ti yio pa awọn ọtá
run.
28 Ẹniti o ba gàn ofin Mose o kú li aini
ãnu nipasẹ ẹlẹri meji tabi mẹta:
29 Melomelo ni ki ẹnyin ki o rò pe o tọ́
si ìjiya kikan, ti o si yẹ fun ẹniti o fi ẹsẹ
tẹ̀ Ọmọ Ọlọrun mọlẹ, ti o si kà ẹ̀jẹ majẹmu
nì, ti a fi yà a si ọ̀tọ, si ohun aimọ́, ti o si
ṣe kẽta si Ẹmí ore-ọfẹ?
30 Nitori awa mọ̀ ẹniti o wipe, Ẹsan ni
ti emi, Oluwa wipe, Emi o gbẹsan. Ati
pẹlu, Oluwa yio ṣe idajọ awọn enia rẹ̀.
31 Ohun ìbẹru ni lati ṣubu si ọwọ́ Ọlọ-
run alãye.
32 Ṣugbọn ẹ ṣe iranti ọjọ iṣaju, ninu eyi,
nigbati a ṣí nyin loju, ẹnyin fi ara gbà ìja
nla ti ipọnju;
33 Lapakan, nigbati nwọn sọ nyin di
iworan nipa ẹ̀gan ati ti ipọnju; ati lapa-
kan, nigbati ẹnyin di ẹgbẹ awọn ti nwọn
lò bẹ̃.
34 Nitori ẹnyin ṣãnu mi ninu ìde mi, ẹ
si fi ayọ̀ gbà ibajẹ ẹrù nyin, bi ẹ ti mọ̀ ninu
ara nyin pe, ẹnyin ni ọrọ̀ ti o duro pẹ, ti o
si dara jù bẹ̃ lọ li ọrun.
35 Nitorina ẹ máṣe já igbẹkẹle nyin
sọnu, ti o ni ẹsan ère nla.
36 Nitori ẹnyin kò le ṣe alaini sũru, pe
lẹhin igbati ẹnyin ba ṣe ifẹ Ọlọrun tan, ki
ẹnyin ki o le gbà ileri.
37 Nitori nigba diẹ si i, ẹniti mbọ̀ yio
de, kì yio si duropẹ.
38 Njẹ nisisiyi olõtọ yio yè nipa igbagbọ́:
ṣugbọn bi ẹnikẹni ba fà sẹhin, ọkàn mi kò
ni inu-didùn si i.
39 Ṣugbọn awa kò si ninu awọn ti nfà
sẹhin sinu egbé; bikoṣe ninu awọn ti o
gbagbọ́ si igbala ọkàn.

## ORI 11.

NJẸ igbagbọ́ ni ipilẹ ohun ti a nreti fun,
ẹrí ohun ti awa kò ri.
2 Nitori nipasẹ rẹ̀ li awọn alàgba fi gbà
ihin rere.
3 Nipa igbagbọ́ li awa mọ̀ pe nipa ọ̀rọ
Ọlọrun li a ti ṣe atiwà awọn aiye, tobẹ̃ ti a
kò fi ohun ti o hàn dá ohun ti a ri.
4 Nipa igbagbọ́ ni Abeli ru ẹbọ didà si
Ọlọrun jù Kaini lọ, nipa eyi ti o fi gbà ẹrí
pe olododo li on, Ọlọrun si njẹri ẹ̀bun rẹ̀:
ati nipa rẹ̀ na, bi o ti kú o nfọhùn sibẹ̀.
5 Nipa igbagbọ́ li a ṣí Enoku nipò pada
ki o máṣe ri ikú; a kò si ri i, nitoriti Ọlọ-
run ṣí i nipò pada: nitori ṣaju iṣipo pada
rẹ̀ o ni ẹrí yi pe, o wù Ọlọrun.
6 Ṣugbọn li aisi igbagbọ́ o ṣoro lati wù
u; nitori ẹniti o ba ntọ̀ Ọlọrun bọ̀, kò le
ṣaima gbagbọ́ pe o mbẹ, ati pe on ni olusẹ-
san fun awọn ti o fi ara balẹ wá a.
7 Nipa igbagbọ́ ni Noa, nigbati a ti ṣe
afiyesi ohun ti a kò ri fun u lọdọ Ọlọrun, o
fi ìbẹru dide, o mura ọkọ̀ (arki) silẹ fun

Digitized by Google

igbala ile rẹ̀; nipa eyi ti o fi dẹbi fun araiye, o si di ajogún ododo ti mbẹ nipa igbagbọ́.
8 Nipa igbagbọ́ ni Abrahamu, nigbati ati pè e lati jade lọ si ibi kan ti on o si gbà nikẹhin ni ilẹ-ini, o gbagbọ́; o si jade lọ, kò mọ ibiti on gbé nrè.
9 Nipa igbagbọ́ li o ṣe atipo ni ilẹ ileri na, bi ẹnipe ni ilu àjeji, o ngbé inu agọ́, pẹlu Isaaki ati Jakọbu, awọn ajogún ileri na pẹlu rẹ̀:
10 Nitoriti o nwoye ilu kan ti o ni ipilẹ̀, ẹniti o tẹ̀ ẹ ti o si ṣe e ni Ọlọrun.
11 Nipa igbagbọ́ ni Sara tikararẹ̀ pẹlu fi ni agbara lati lóyun, o si bímọ nigbati o kọja ọjọ aiye tan, nitoriti o kà ẹniti o ṣe ileri si olõtọ.
12 Nitorina li ọ̀pọlọpọ ṣe hù jade lara ẹnikan, ani lara ẹniti o dabi okú, ọ̀pọ bi irawọ oju ọrun li ọ̀pọlọpọ, ati bi iyanrin eti okun li ainiye.
13 Awọn wọnyi gbogbo li o kú nipasẹ igbagbọ́, ti nwọn kò ri ileri na gbà, ṣugbọn nwọn ti ri i li òkere rere, nwọn si ti mọ̀ ninu wọn, nwọn sì di wọn mu, nwọn si jẹwọ pe alejò ati atipo li awọn lori ilẹ aiye.
14 Nitoripe awọn ti o nsọ irú ohun bẽ, nwọn sọ gbangba pe, nwọn nwá ilu kan kiri.
15 Ati nitõtọ, ibaṣepe nwọn ṣe aniyan ilu na, nibiti nwọn gbé ti jade wá, nwọn ati wá ọ̀na lati pada.
16 Ṣugbọn nisisiyi nwọn nfẹ ilu kan ti o dara jù bẽ lọ, eyini ni ti ọrun: nitorina Ọlọrun kò si tiju li a ti mã pè li Ọlọrun ti wọn; nitori o ti pèse ilu kan silẹ fun wọn.
17 Nipa igbagbọ́ ni Abrahamu, nigbati a dán a wò, o fi Isaaki rubọ: ẹniti o si ti gbà ileri nì, o fi ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo na rubọ,
18 Niti ẹniti a wipe, Ninu Isaaki li a o ti pè irú-ọmọ rẹ:
19 Ti o si nkà a si pe, Ọlọrun tilẹ le jí i dide kuro ninu okú; nipasẹ eyina li o gbà a li apẹrẹ.
20 Nipa igbagbọ́ ni Isaaki sure fun Jakọbu ati Esau ni idi ohun ti mbọ̀wa.
21 Nipa igbagbọ́ ni Jakọbu, nigbati o wà ni ibulẹ ikú, o sure fun awọn ọmọ Josefu mejeji; o foribalẹ, o fi ara tì ori ọpá titẹ̀ rẹ̀.
22 Nipa igbagbọ́ ni Josefu, nigbati nkú lọ, o ranti atijade awọn ọmọ Israeli; o si fi aṣẹ fun wọn nipa egungun okú on.
23 Nipa igbagbọ́ ni Mose, nigbati a bí i, a pa a mọ́ li oṣù mẹta lọdọ awọn õbi rẹ̀, nitoriti nwọn ri i li ọmọ rere; nwọn kò si bẹ̀ru aṣẹ ọba.
24 Nipa igbagbọ́ ni Mose, nigbati o dàgba tan, o kọ̀ ki a mã pè on li ọmọ ọmọbirin Farao;
25 O kuku yàn ati mã bá awọn enia Ọlọrun jìya iponju, jù ati ma jẹ aiye ẹ̀ṣẹ lọ nigba diẹ;
26 O nkà ẹ̀gan Kristi li ọrọ̀ nla jù iṣura Egipti lọ: nitoriti o bu iyìn fun ẹsan ère na.
27 Nipa igbagbọ́ li o kọ̀ Egipti silẹ, kò bẹ̀ru ibinu ọba: o sá foritì i, bi ẹnipe o nri ẹniti iṣe airi.
28 Nipa igbagbọ́ li o rubọ irekọja, ati ibuwọ́n ẹ̀jẹ, ki ẹniti npa awọn akọbi ọmọ ki o má ba fi ọwọ́ kàn wọn.
29 Nipa igbagbọ́ ni nwọn là okun pupa kọja bi ẹnipe ni iyangbẹ ilẹ: ti awọn ara Egipti danwò lati ṣe, nwọn rì.
30 Nipa igbagbọ́ li odi Jeriko wó lulẹ, lẹhin igbati a yi wọn ká ni ijọ meje.
31 Nipa igbagbọ́ ni Rahabu panṣaga obirin kò ṣegbé pẹlu awọn ti kò gbagbọ́, nigbati o tẹwọgbà awọn amí li alafia.
32 Ewo li emi o si tun mã wi si i? nitoripe ìgba yio kùna fun mi lati sọ ti Gideoni, ati Baraku, ati Samsoni, ati Jefta; ti Dafidi, ati Samueli, ati ti awọn woli:
33 Awọn ẹni nipasẹ igbagbọ́ ti nwọn ṣẹgun ilẹ ọba, ti nwọn ṣiṣẹ ododo, ti nwọn gbà ileri, ti nwọn dì awọn kiniun li ẹnu,
34 Ti nwọn pa agbara mimu iná kú, ti nwọn yọ kuro li ẹnu idà, ninu ailera ti a sọ wọn di alagbara, nwọn di akọni ni ìja, nwọn lé ogun awọn àjeji sá.
35 Awọn obirin ngbà okú wọn ti a ji dide laye: a si dá awọn ẹlomiran lóro, nwọn kò gbà idasilẹ; ki nwọn ki o le ri ajinde gbà ti o darajù:
36 Awọn ẹlomiran si ni idanwò ifi ṣe ẹlẹyà, ati ti ìna, nitõtọ, ti ìde ati ti isọ sinu tubu pẹlu:
37 A sọ wọn li okuta, a fi ayùn rẹ́ wọn meji, a dán wọn wò, a fi idà pa wọn: nwọn nrìn kákiri ni wiwọ̀ awọ agutan ati awọ ewurẹ; ninu aini, olupọnju, ẹni idaloro;
38 (Ẹniti aiye kò yẹ fun:) nwọn nrìn ká kiri ninu aṣálẹ, ati lori òke-nla, ati ninu ihò ati ninu ihò abẹ ilẹ.
39 Gbogbo awọn wọnyi ti nwọn ni ihin rere nipa igbagbọ́, kò si ri ileri na gbà:
40 Ọlọrun si ti pèse ohun ti o darajù silẹ fun wa, pe li aisi wa, a kò le mu wọn pé.

Digitized by Google

## ORI 12.

NJẸ nitorina bi a ti fi awọsanma ẹlẹri papọ̀ tobẽ̩ yi wa ká, ẹ jẹ ki a fi ohun iwuwo gbogbo lẹlẹ li apakan, ati ẹ̀ṣẹ ti kò ṣoro lati lẹ̀ mọ́ wa, ki a si mã fi sũru sure ije ti a gbé kalẹ niwaju wa,

2 Ki a mã wò Jesu ti iṣe olupilẹ̀ṣẹ ati olupari igbagbọ́ wa; ẹni, nitori ayọ̀ ti a gbé kalẹ niwaju rẹ̀, ti o fi ara gbà agbelebu na, kò kà itiju na si, o si joko li ọwọ́ ọtún itẹ́ Ọlọrun.

3 Sà ro ti ẹniti o fi ara gbà irú iṣòdisi ẹlẹṣẹ bi eyi si ara rẹ̀, ki ãrẹ̀ ki o má ba mu nyin, ki agara ki o má ba dá ọkàn nyin.

4 Ẹnyin kò ti ikọju ìja si i di ẹ̀jẹ ninu ìja nyin si ẹ̀ṣẹ.

5 Ẹnyin si ti gbagbé ọ̀rọ iyanju ti mba nyin sọ bi awọn ọmọ pe, Ọmọ mi, máṣe gàn ibawi Oluwa, ki agara ki o máṣe dá ọ nigbati a ba nti ọwọ́ rẹ̀ ba ọ wi:

6 Nitoripe ẹniti Oluwa fẹ on ni ibawi, a si mu nà olukuluku ọmọ ti o gbà.

7 Bi ẹnyin ba fi ara gbà ìna, Ọlọrun ṣe si nyin bi ãti ṣe si awọn ọmọ; nitoripe ọmọ wo ni mbẹ ti baba ki ibawi?

8 Ṣugbọn bi ẹnyin ba wà li aibawi, ninu eyiti gbogbo enia ni ipín, njẹ ọmọ àle ni nyin, ẹ kì iṣe ọmọ.

9 Pẹlupẹlu awa ni baba ni ti ara wa ti o ntọ́ wa, awa si mbù ọlá fun wọn: awa kì yio kuku foribalẹ fun Baba awọn ẹmí ki a si yè?

10 Nitoripe nitõtọ li ọjọ diẹ ni nwọn ntọ́ wa nipa ifẹ ti ara wọn; ṣugbọn on fun ère wa, ki awa ki o le ṣe alabapin ìwa mimọ́ rẹ̀.

11 Ṣugbọn gbogbo ibawi, nigbati o wà, a kò rò pe inu-didùn ni, bikoṣe ibinujẹ: ṣugbọn nikẹhin a so eso alafia ododo fun awọn ti a lò nipasẹ rẹ̀.

12 Nitorina ẹ gbé ọwọ́ soke ti o rọ̀ silẹ, ati ẽkun ailera;

13 Ki ẹ si ṣe ọ̀na títọ fun ẹsẹ nyin, ki eyiti o wọ́ ki o máṣe yẹ̀ kuro loju ọ̀na; bikoṣe ki a kuku mu u larada.

14 Ẹ mã tọ̀ alafia lẹhin pẹlu enia gbogbo, ati ìwa mimọ́, li aisi eyini kò si ẹniti yio ri Oluwa:

15 Ni afojusọna gidigidi ki ẹnikẹni ki o máṣe kùna ore-ọfẹ Ọlọrun; ki gbòngbo kikorò kan ki o má ba hù soke ki o yọ nyin lẹnu, ọ̀pọlọpọ a si ti ipa rẹ̀ di aimọ;

16 Ki àgbere, tabi enia lasan kan bi Esau, ki o máṣe si, ẹniti o ti itori òkele onjẹ kan tà ogún ibí rẹ̀.

17 Nitoripe ẹnyin mọ̀ nikẹhin rẹ̀, nigbati on wa ifẹ jogún ibukun, bi ati kọ̀ ọ: ko sá ri àye ati pa ìwa rẹ̀ dà, bi o tilẹ ti fi omije jòwere rẹ̀ gidigidi.

18 Nitoripe ẹnyin kò wá si òke, ti a le fi ọwọ́ kàn, ti iná si njó, tabi si dudu, ati òkunkun, ati ẹfũfu,

19 Ati iró ipè, ati ohùn ọ̀rọ; ti awọn ti o gbọ́ bẹ̀bẹ pe, ki a máṣe sọ ọ̀rọ na si wọn mọ́:

20 (Nitoripe ara wọn kò le gbà ohun ti a palaṣẹ, Bi o tilẹ ṣe tobẽ̩ bi ẹranko kan fi ara kàn òke na, okuta li a o sọ lù u, tabi ã gún u li ọ̀kọ pa:

21 Iran na si lẹrù tobẽ̩, ti Mose wipe, Emi bẹ̀ru gidigidi mo si wariri:)

22 Ṣugbọn ẹnyin wá si òke Sioni, ati si ilu Ọlọrun alãye, si Jerusalemu ọrun, ati si ẹgbẹ awọn angeli ainiye,

23 Si iwọpọ̀ ẹgbẹ ati ijọ enia Ọlọrun akọbi, ti a ti kọwe rẹ̀ li ọrun, ati sọdọ Ọlọrun Onidajọ gbogbo enia, ati sọdọ awọn ẹmí olõtọ enia ti a ṣepé,

24 Ati sọdọ Jesu onilaja majẹmu titun, ati si ibi ẹ̀jẹ ibuwọ́n nì, ti nsọ̀rọ ohun ti o darajù ti Abeli lọ.

25 Kiyesi i ki ẹ máṣe kọ̀ ẹniti nsọ̀rọ. Nitori bi awọn ẹniti o kọ̀ ẹniti nsọ̀rọ li aiye kò ba bọ́, melomelo li awa kì yio le bọ́, bi awa ba yipada kuro lọdọ ẹniti nsọ̀rọ lati ọrun wá:

26 Ohùn ẹniti o mì aiye nigbana: ṣugbọn nisisiyi o ṣe ileri, wipe, Lẽkan si i emi kì yio mì kìki aiye nikan, ṣugbọn ọrun pẹlu.

27 Ati ọ̀rọ na yi, Lẽkan si i, o ni ìmọ iṣípo pada nkan wọnni ti a ti mì, bi ohun ti a dá, ki ohun ti a kò le mì ki o gbé bẽ̩.

28 Nitorina bi awa ti ngbà ilẹ ọba ti a kò le mì, jẹ ki a dì ore-ọfẹ mu, nipa eyi ti a ba fi le mã fi itẹwọgbà sìn Ọlọrun pẹlu ọ̀wọ ati ìbẹru Ọlọrun.

29 Nitoripe Ọlọrun wa ajonirun iná ni.

## ORI 13.

KI ifẹ ará ki o pẹ titi.

2 Ẹ máṣe gbagbé lati mã ṣe alejò; nitoripe nipa bẽ̩ li awọn ẹlomiran ṣe awọn angeli li alejò laimọ̀.

3 Ẹ ṣe iranti awọn ti mbẹ ninu ìde, bi ẹniti a dè pẹlu wọn; ati awọn ti njìya ibi, bi ẹnipe ẹnyin tikara nyin pẹlu mbẹ ninu ara.

4 Igbéyawo ni iyìn ninu ohun gbogbo, ori-ẹní a si ṣe alailẽri: ṣugbọn awọn àgbere ati awọn panṣaga li Ọlọrun yio dá lẹjọ.

5 Ki ìwa-aiye nyin ki o ṣe alaini ojukò-

Digitized by Google

koro; ki ohun ti ẹ si ni ki o to fun nyin:
nitori ti o ti wipe, Emi kì yio fi ọ silẹ titi,
tabi ki nkọ̀ ọ silẹ.
6 Bẹ̃ li awa si le ma fi igboiya wipe,
Oluwa li oluranlọwọ mi, emi kì yio bẹru
ohun ti enia yio ṣe si mi.
7 Ranti awọn ti nṣe olori nyin, ti nwọn
sọ ọ̀rọ Ọlọrun fun nyin: ki ẹ mã rò opin
ìwa-aiye wọn, ati igbagbọ́ wọn ki ẹ mã tọ̀
lẹhin.
8 Jesu Kristi ọkanna li aná, ati li oni,
ati titi lai.
9 Ẹ máṣe jẹ ki a fi onirũru ati ẹkọ́ àjeji
gbá nyin kiri. Nitoripe ohun rere ni bi a
ba fi ore-ọfẹ fi idi àiya kalẹ; kì iṣe ifi onjẹ
ṣe, ti kò ṣe anfani fun awọn ti o ti nrìn
ninu rẹ̀.
10 Awa ni pẹpẹ kan, ninu eyi ti awọn ti
nsìn agọ́ kò li agbara lati mã jẹ.
11 Nitoripe ara awọn ẹran wọnni, ẹ̀jẹ
eyiti a mu wá sinu ibi mimọ́ lati ọwọ́ olori
alufa wá nitori ẹ̀ṣẹ, a sun wọn lẹhin ibudo.
12 Nitorina Jesu pẹlu, ki o le fi ẹ̀jẹ ara
rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́, o jìya lẹhin bode.
13 Nitorina ẹ jẹ ki a jade tọ̀ ọ lẹhin lọ
si ibudo, ki a mã rù ẹ̀gan rẹ̀.
14 Nitoripe awa kò ni ilu ti o duro pẹ
nihinyi, ṣugbọn awa nwá ọkan ti mbọ̀.
15 Njẹ nipasẹ rẹ̀, ẹ jẹ ki a ru ẹbọ iyìn si
Ọlọrun nigbagbogbo, eyini ni eso ète wa,
lati mã fi ọpẹ́ fun orukọ rẹ̀.
16 Ṣugbọn ati mã ṣõre ati lati mã pin-
funni ẹ máṣe gbagbé; nitori irú ẹbọ bẹ̃ ni
inu Ọlọrun dùn si jọjọ.
17 Ẹ gbà awọn ti nṣe olori nyin gbọ́, ki
ẹ si fi ori nyin balẹ: nitori nwọn nṣọ ẹṣọ
nitori ọkàn nyin, bi awọn ti kò gbọdọ mã
ṣíro, ki nwọn ki o le fi ayọ̀ ṣe e, li aisi ibi-
nujẹ: nitori eyini ṣe ailere fun nyin.
18 Ẹ gbadura fun wa: nitori awa gbẹ-
kẹle pe awa ni ọkàn rere, ninu ohun gbo-
gbo a nfẹ ki a mã gbé lododo ìwa.
19 Ṣugbọn emi kuku bẹ̀ nyin lati mã ṣe
eyi, ki a le tète dá mi silẹ fun nyin.
20 Njẹ nisisiyi ki Ọlọrun alafia, ti o mu
Jesu Oluwa wa ti inu okú wá, Oluṣọ-agutan
nla nì ti awọn agutan rẹ̀, nipasẹ ẹ̀jẹ majẹ-
mu aiyeraiye.
21 Ki o mu nyin pé ninu iṣẹ rere gbogbo
lati ṣe ifẹ rẹ̀, ti nṣiṣẹ ninu nyin lati mã ṣe
eyi ti o ṣe inu-didùn gidigidi li oju rẹ̀, ni-
pasẹ Jesu Kristi; ẹniti ogo wà fun lai ati
lailai. Amin.
22 Emi si bẹ̀ nyin, ará, ẹ gbà ọ̀rọ iyanju;
mo sá ti kọ iwe si nyin li ọ̀rọ diẹ.
23 Ki ẹ mọ̀ pe a dá Timoteu arakọnrin
wa silẹ; pẹlu ẹni, bi o ba de nisisiyi, emi
o ri nyin.
24 Ẹ kí gbogbo awọn ti nṣe olori nyin,
ati gbogbo awọn enia mimọ́. Awọn ará ti
Itali kí nyin.
25 Ki ore-ọfẹ ki o wà pẹlu gbogbo nyin.
Amin.

A kọ ọ si awọn Heberu lati Itali wá,
nipa ọwọ́ Timoteu.

EPISTELI TI

# JAKỌBU

FUN ENIA GBOGBO.

## ORI 1.

JAKỌBU, iranṣẹ Ọlọrun ati ti Jesu Kristi
Oluwa, si awọn ẹ̀ya mejila ti o túka
kiri, alafia.
2 Ẹnyin ará mi, nigbati ẹnyin ba bọ́
sinu onirũru idanwò, ẹ kà a si ayọ̀ gbogbo;
3 Ki ẹnyin ki o si mã mọ̀ eyi pe, idanwò
igbagbọ́ nyin ni iṣiṣẹ sũru.
4 Ṣugbọn ẹ jẹ ki sũru ki o ṣiṣẹ aṣetan,
ki ẹnyin ki o le pé, ki ẹ si ṣọkan, laikù
ohun kan.
5 Bi ẹnikan ninu nyin ba ṣe alailọ́gbọn,
ki o bère lọwọ Ọlọrun, ẹniti ifi fun gbogbo

enia li ọ̀pọlọpọ, ti kì isi ibaniwi; a o si fifun u.

6 Ṣugbọn ki o bère ni igbagbọ́, li aiṣiyemeji. Nitori ẹniti o nṣiyemeji, o dabi riru omi okun, ti nti ọwọ́ afẹfẹ bì siwa bì sẹhin.

7 Nitori ki oluwarẹ̀ na ki o máṣe rò pe, on o ri nkan gbà lọwọ Oluwa.

8 Enia oniyemeji kò le mu ara duro ni ọ̀na rẹ̀ gbogbo.

9 Ṣugbọn ki arakọnrin onirẹlẹ ki o mã yọ̀ ni ti a gbé e ga:

10 Ṣugbọn ọlọrọ̀, ni ti a rẹ̀ ẹ silẹ: nitori bi itanná koriko bẹ̃ni yio kọja lọ.

11 Nitori bi õrùn ba ti là ti on ti oru mimu, a si mã gbẹ koriko, ati itanná rẹ̀ a si rẹ̀ silẹ, ati ẹwà iṣe rẹ̀ a si parun: bẹ̃ gẹgẹ li ọlọrọ̀ yio si parẹ ni ọ̀na rẹ̀.

12 Ibukún ni fun ọkọnrin ti o fi ọkàn rán idanwò: nitori igbati a ba dán a wò, yio gbà ade ìye, ti Oluwa ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ.

13 Nigbati a ba dán ẹnikẹni wò, ki o máṣe wipe, lati ọwọ́ Ọlọrun wá li a ti dán mi wò: nitori a kò le fi buburu dán Ọlọrun wò, bẹ̃ni kì idán ẹnikẹni wò:

14 Ṣugbọn olukuluku li o di ẹni-idanwò, nigbati a ba ti ọwọ́ ifẹkufẹ ara rẹ̀ fà a lọ, ti a si tàn a jẹ.

15 Njẹ nigbati ifẹkufẹ ba lóyun, a bí ẹ̀ṣẹ: ati ẹ̀ṣẹ, nigbati a ba pari rẹ̀ tan, a bí ikú.

16 Ẹ máṣe ṣìna, ẹnyin ará mi olufẹ.

17 Gbogbo ẹ̀bun rere ati ẹ̀bun ti o pé, oke li o ti wá, o si sọkalẹ lati ọdọ Baba imọlẹ wá, lọdọ ẹniti kò si onirũru ìwa, bẹ̃ni kò si ojiji iyipada.

18 Ninu ifẹ ara rẹ̀ li o fi ọ̀rọ otitọ bí wa, ki awa ki o le ṣe irú akọbi ninu awọn ẹda rẹ̀.

19 Nitorina, ará mi olufẹ, ki olukuluku enia ki o mã yara lati gbọ́, ki o lọra lati fọhùn, ki o lọra lati binu:

20 Nitori ibinu enia kì iṣiṣẹ ododo Ọlọrun.

21 Nitorina ẹ fi ẽri ati buburu aṣeleke gbogbo lelẹ li apakan, ki ẹnyin ki o si fi ọkàn tutù gbà ọ̀rọ alọmọ nì, ti o le gbà ọkàn nyin là.

22 Ṣugbọn ki ẹnyin ki o ṣe oluṣe ọ̀rọ na, ki ẹ máṣe olugbọ́ nikan, nititàn ara nyin jẹ.

23 Nitori bi ẹnikan ba ṣe olugbọ́ ọ̀rọ na, ti kò si ṣe oluṣe, o dabi ọkọnrin ti o nwò oju-iyoju rẹ̀ ninu awojiji:

24 Nitori nigbati o wò ara rẹ̀ tan, o si ba tirẹ̀ lọ, lojukanna o si gbagbé irú enia bi on ti ri.

25 Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba wò inu ofin omnira nì ti o pé, ti o si duro sinu rẹ̀, ti on kò ṣe olugbọ́ onigbagbé, bikoṣe oluṣe iṣẹ na, oluwarẹ̀ li a o bukún fun ninu iṣẹ rẹ̀.

26 Bi ẹnikan ninu nyin ba dabi ẹnipe o nsìn Ọlọrun, ti kò si kó ahọn rẹ̀ ni ijanu, ṣugbọn ti o ntàn ọkàn ara rẹ̀ jẹ, ìsin Ọlọrun oluwarẹ̀ asan ni.

27 Ìsin mimọ́ ati ailabawọn niwaju Ọlọrun ati Baba on li eyi, ati mã bojuwò awọn alaini-baba ati awọn opó ninu ipọnju wọn, ati ki o si mã pa ara rẹ̀ mọ́ kuro lọdọ araiye li ailabawọn.

## ORI 2.

ARÁ mi, ẹ máṣe fi ojusaju enia ní igbagbọ́ Oluwa wa Jesu Kristi, Oluwa ogo.

2 Nitori bi ọkọnrin kan ba wá si ajọ nyin, ti on ti oruka wura, ati li aṣọ rere, ti talakà kan si wá pẹlu li aṣọ ẽri;

3 Ti ẹnyin si buyìn fun ẹniti o wọ̀ aṣọ daradara, ti ẹ si wi fun u pe, Iwọ joko nihinyi ni ibi rere; ati, fun talakà na pe, Iwọ duro nibẹ̀, tabi pe, wá joko labẹ apoti itisẹ mi:

4 Ẹnyin kò nṣe ojusaju ninu ara nyin, ẹnyin kò si di onidajọ ironu buburu?

5 Ẹ fi etí silẹ, ẹnyin ará mi olufẹ, Ọlọrun kò ti yàn talakà aiye yi ṣe ọlọrọ̀ ni igbagbọ́ ati arole ijọba na, ti o ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ?

6 Ṣugbọn ẹnyin ti bù talakà kù. Awọn ọlọrọ̀ ki npọ́n nyin loju, ti nwọn si ntì nyin lọ si ibujoko idajọ?

7 Awọn ki nsọ ọ̀rọ buburu si orukọ iyebiye nì ti a fi npè nyin?

8 Bi ẹnyin ba nṣe olú ofin nì gẹgẹ bi iwe-mimọ́: Iwọ fẹ ẹnikeji rẹ bi ara rẹ, ẹnyin ṣe rere:

9 Ṣugbọn bi ẹnyin ba nṣe ojusaju si enia, ẹnyin da ẹ̀ṣẹ, nipa ofin li a o fi oyé yé nyin bi arufin.

10 Nitoripe ẹnikẹni ti o ba pa ofin gbogbo mọ́, ṣugbọn ti o ba ṣẹ̀ ni ipa kan, o jẹbi gbogbo rẹ̀.

11 Nitori on na ti o wipe, Máṣe panṣaga, on li o si wipe, Máṣe pania. Njẹ bi iwọ kò ṣe panṣaga, ṣugbọn bi iwọ ba pania, iwọ di arufin.

12 Ẹ mã sọ bẹ̃, ẹ si mã ṣe bẹ̃, bi awọn ti a o fi ofin omnira dá li ẹjọ.

13 Nitori ẹniti kò ṣãnu, on li a o si fi aiṣãnu ṣe idajọ fun; ãnu si leri si idajọ.

14 Ere kini, ará mi, bi ẹnikan tilẹ wipe on ni igbagbọ́, ti kò si ni iṣẹ? igbagbọ́ rẹ̀ le gbà a là bi?

Digitized by Google

15 Bi arakọnrin tabi arabirin kan ba wà
ni ìhoho, ti o si ṣe aili onjẹ õjọ,
16 Ti ẹnikan ninu nyin si wi fun wọn
pe, Ẹ mã lọ li alafia, ki ara nyin ki o gbó-
na, ki ẹ si yó ; ṣugbọn ẹ kò fi nkan wọnni
ti nwọn ṣe aini fun ara : ère kili eyini ?
17 Gẹgẹ bẹ̃ni igbagbọ́, bi kò ba ni iṣẹ, o
kú, on nikan ni.
18 Ṣugbọn ẹnikan le wipe, Iwọ ni igba-
gbọ́, emi si ni iṣẹ : fi igbagbọ́ rẹ hàn mi li
aini iṣẹ, emi o si fi igbagbọ́ mi hàn ọ nipa
iṣẹ mi.
19 Iwọ gbagbọ́ pe Ọlọrun kan ni mbẹ ;
iwọ ṣe rere : awọn ẹmí èṣu gbagbọ́ pẹlu,
nwọn si warìri.
20 Ṣugbọn iwọ enia onifefe nfẹ mọ̀ pe,
igbagbọ́ li aini iṣẹ okú ni ?
21 Nipa iṣẹ ki a dá Abrahamu baba wa
lare, nigbati o fi fi Isaaki ọmọ rẹ̀ rubọ lori
pẹpẹ ?
22 Iwọ kò ri bi igbagbọ́ ti ṣe pẹlu iṣẹ
rẹ̀, ati nipa iṣẹ ni igbagbọ́ di pipé ?
23 Iwe mimọ́ si ṣẹ ti o wipe, Abrahamu
gbà Ọlọrun gbọ́, a si kà a si i fun ododo :
a si pè e li ọrẹ Ọlọrun.
24 Njẹ ẹnyin ri i pe nipa iṣẹ li a ndá
enia lare, kì iṣe nipa igbagbọ́ nikan.
25 Gẹgẹ bẹ̃ ki a dá Rahabu panṣaga lare
pẹlu nipa iṣẹ, nigbati o gbà awọn onṣẹ, ti o
si rán wọn jade li ọ̀na miran ?
26 Nitori bi ara ti kò li ẹmí ti di okú,
bẹ̃ni igbagbọ́ li aini iṣẹ o kú pẹlu.

## ORI 3.

ARÁ mi, ẹ máṣe olukọni pipọ, ki ẹnyin
ki o mọ̀ pe awa ni yio jẹbi pọ̀ju.
2 Nitori ninu ohun pipọ ni gbogbo wa
nṣìṣe. Bi ẹnikan kò ba ṣìṣe ninu ọ̀rọ, on
na li ẹni pipé, on li o si le kó gbogbo ara
ni ijanu.
3 Kiyesi i, awa ama fi ijanu bọ̀ ẹṣin li
ẹnu, ki nwọn ki o le gbọ́ ti wa ; gbogbo
ara wọn li awa si nyi ká kiri.
4 Kiyesi ọkọ̀ pẹlu, bi nwọn ti tobi to nì,
ti nti ọwọ ẹfũfu nla fẹ́ kiri, ṣugbọn itọkọ̀
pẹlẹbẹ li a fi ndari wọn kiri, nibikibi ti o
wù olori ọkọ̀.
5 Bẹ̃ gẹgẹ li ahọn jasi ẹ̀ya kekere, ti o si
nleri ohun nla. Kiyesi igi nla ti iná ke-
kere sun jóna !
6 Ahọn si ni iná, aiye ẹ̀ṣẹ : bẹ̃li ahọn ri
ninu awọn ẹ̀ya ara wa, ti o bà gbogbo ara
jẹ, o si tinabọ ipa ayika ẹda ; a si ti on bọ
iná ọrun apadi.
7 Nitori gbogbo ẹda ti ẹranko, ati ti
ẹiyẹ, ati ti ejò, ati ti ohun ti mbẹ li okun,
li a ntù loju, lati ọwọ́ ẹda enia wá li a ti
ntù wọn loju :
8 Ṣugbọn ahọn li ẹnikẹni kò le tù loju :
ohun buburu alaigbọran ni, o kún fun oró
ikú.
9 On na li awa fi nyìn Ọlọrun ani Baba ;
on na li a si fi mbú enia, ti a dá li aworan
Ọlọrun.
10 Lati ẹnu kanna ni iyìn ati ẽbú ti
njade. Ará mi, nkan wọnyi kò yẹ ki o ri
bẹ̃.
11 Orisun ama sun omi tutù ati kikorò
jade lati ojusun kanna wá bi ?
12 Ará mi, igi ọpọtọ le so eso olifi bi ?
tabi ajara le so eso ọpọtọ ? bẹ̃li orisun kan
kò le sun omi iyọ̀ ati omi tutù.
13 Tali ọlọ́gbọn ti a si fi imoye wọ̀ ninu
nyin ? ẹ jẹ ki o fi iṣẹ rẹ̀ hàn pẹlu ọgbọ́n ìwa
tutù lati inu ìwa rere jade wá.
14 Ṣugbọn bi ẹnyin ba ni irira kikorò
ati ìja li àiya nyin, ẹ má ṣeféfe, ẹ má si
ṣeke si otitọ.
15 Ọgbọ́n yi kò ti oke sọkalẹ wá, ṣugbọn
ti aiye ni, ti ẹda ni, ti ẹmí èṣu ni.
16 Nitori ibiti irira on ìja gbé wà, nibẹ̀
ni rudurudu ati iṣẹ buburu gbogbo wà.
17 Ṣugbọn ọgbọ́n ti o ti oke wá, a kọ́
mọ́, a si jẹ alafia, a ṣe pẹlẹ, kò ṣoro lati bẹ,
o kún fun ãnu ati fun eso rere, li aiṣegbe,
ati li aiṣe agabagebe.
18 Eso ododo li a ngbìn li alafia lati ọwọ́
awọn ti nṣe alafia wá.

## ORI 4.

NIBO li ogun on ìja ti wá ninu nyin ?
ninu eyi ha kọ ? ninu ifẹ ara nyin, ti
njagun ninu awọn ẹ̀ya ara nyin ?
2 Ẹnyin nfẹ, ẹ kò si ni : ẹnyin npa,
ẹnyin si njowú, ẹ kò si le ri gbà : ẹnyin
njà, ẹnyin si njagun, bẹ̃li ẹ ko ni, nitori ti
ẹnyin kò bère.
3 Ẹnyin bère, ẹ kò si ri gbà, nitori ti
ẹnyin ṣì bère, ki ẹnyin ki o le lò o si ifẹ ara
nyin.
4 Ẹnyin panṣaga ọkọnrin, ati panṣaga
obirin, ẹnyin kò mọ̀ pe ibárẹ aiye ọtá ni
lọdọ Ọlọrun ? nitori ẹnikẹni ti yio ba ṣe
ọrẹ́ aiye on li ọtá Ọlọrun.
5 Ẹnyin ṣebi iwe mimọ́ wi lasan pe, Ẹmi
ti o wà ninu nyin o ṣe ilara ijowú ?
6 Ṣugbọn o nfun-ni li ore-ọfẹ si i. Nito-
rina li o ṣe wipe, Ọlọrun kọjùjasi awọn
agberaga, ṣugbọn o fi ore-ọfẹ fun awọn
onirẹlẹ ọkàn.
7 Nitorina ẹ fi ori nyin balẹ fun Ọlọrun.
Ẹ kọjùjasi Èṣu, on o si sá kuro lọdọ nyin.

Digitized by Google

8 Ẹ sunmọ Ọlọrun, on o si sunmọ nyin.
Ẹ wẹ̀ ọwọ́ nyin nù, ẹnyin ẹlẹṣẹ ; ẹ si wẹ̀
àiya nyin mọ́ ẹnyin oniyemeji.
9 Ki inu nyin ki o bajẹ, ki ẹ si gbàwẹ,
ki ẹ si mã sọkun : ẹ jẹ ki ẹrin nyin ki o di
àwẹ, ati ayọ̀ nyin ki o di ikãnu.
10 Ẹ rẹ̀ ara nyin silẹ niwaju Oluwa, on
o si gbé nyin leke.
11 Ará, ẹ máṣe sọ̀rọ ibi si ara nyin.
Ẹniti o ba nsọ̀rọ ibi si arakọnrin rẹ̀, ti o si
nṣe idajọ arakọnrin rẹ̀, o nsọ̀rọ ibi si ofin,
o si nṣe idajọ si ofin : ṣugbọn bi iwọ ba nṣe
idajọ ofin, iwọ kì iṣe oluṣe ofin, bikoṣe
onidajọ.
12 Olofin kan ni mbẹ, ẹniti o le gbàni
là, ti o si le parun : iwọ tani nì ti nṣe idajọ
ẹnikeji ?
13 Ẹ wá nisisiyi, ẹnyin ti nwipe, Loni
tabi lọla awa o lọ si ilu kan bayi, awa o si
gbé ibẹ̀ li ọdún kan, awa o mã ṣòwo, awa o
si ma jère :
14 Nigbati ẹnyin kò mọ̀ ohun ti yio hù
lọla. Nitori kili ẹmí nyin ? Ikũku sá tilẹ
ni, ti o hàn nigba diẹ, nigbati o ṣe a si
túka lọ.
15 Eyi li ẹnyin iba mã wi pe, Bi Ọlọrun
fẹ, awa o wà lãye, awa o si ṣe eyi tabi
eyini.
16 Ṣugbọn nisisiyi ẹnyin nṣeféfe ninu
ileri nyin : gbogbo irú iṣeféfe bẹ̃ buburu
ni.
17 Nitorina ẹniti o ba mọ̀ rere iṣe ti kò
si ṣe e, ẹ̀ṣẹ ni fun u.

ORI 5.

EWA nisisiyi, ẹnyin ọlọrọ̀, ẹ mã sọkun
ki ẹ si mã kigbe nitori òṣi nyin ti
mbọ̀wa ta nyin.
2 Ọrọ̀ nyin dibajẹ, ati aṣọ nyin di jijẹ
fun kòkoro.
3 Wura on fadaka nyin dipara ; ipara
wọn ni yio si ṣe ẹlẹri si nyin, on ni yio si jẹ
ẹran ara nyin bi iná. Ẹnyin ti kó iṣura jọ
dè ọjọ ikẹhin.
4 Kiyesi i, ọ̀ya iṣẹ awọn alagbaṣe ti o ti
ṣe ipalẹmọ́ nkan oko nyin, ti a ti ọwọ́ nyin
nipa irẹ́jẹ kìwọ, o nkigbe : ati igbe awọn ti
o ṣe akojọ, o wọ̀ etí Oluwa ọmọ-ogun lọ.
5 Ẹnyin njẹ ohun didùn li aiye, ẹ ti njẹ
ajẹyó ; ẹnyin ti mbọ́ àiya nyin, bi ẹnipe li
ọjọ pipa.
6 Ẹnyin ti da ẹbi fun, ẹ si ti pa olõtọ ;
on kò kọjùjasi nyin.
7 Nitorina ará, ẹ mu sũru dè atiwá
Oluwa. Kiyesi i, àgbẹ ama duro dè eso
iyebiye ti ilẹ, a si mu sũru fun u pẹ, titi
digba akọrọ̀ ati arọ̀-kuro òjo.
8 Ẹ mu sũru pẹlu ; ẹ fi àiya nyin balẹ :
nitori atiwá Oluwa kù si dẹdẹ.
9 Ẹ máṣe kùn si ọmọnikeji nyin, ará, ki
a máṣe dá nyin lẹbi : kiyesi i, onidajọ duro
li ẹnu ilẹkun.
10 Ará mi, ẹ fi awọn woli ti o ti nsọ̀rọ li
orukọ Oluwa, ṣe apẹrẹ ìya ijẹ, ati sũru imu.
11 Sawò o, awa ama kà awọn ti o duro
li ẹni abukún fun. Ẹnyin ti gbọ́ ti sũru
Jobu, ẹnyin si ri igbẹhin Oluwa ; pe Oluwa
kún fun iyọ́nu, ãnu rẹ̀ si rọ̀.
12 Ṣugbọn jù ohun gbogbo lọ, ará mi, ẹ
máṣe búra, iba ṣe ifi ọrun bú, tabi ifi ilẹ bú,
tabi ifi èpekepe bú : ṣugbọn jẹ ki bẹ̃ni nyin
ki o jẹ bẹ̃ni ; ati bẹ̃kọ ki o jẹ bẹ̃kọ ; ki
ẹnyin ki o máṣe bọ́ sinu ẹbi.
13 Inu ẹnikẹni ha bajẹ ninu nyin bi ? jẹ
ki o gbadura. Inu ẹnikẹni dùn ? jẹ ki o
kọrin mimọ́.
14 Ẹnikẹni ṣe aisan ninu nyin bi ? ẹ jẹ
ki o pè awọn alàgba ijọ, ki nwọn ki o gba-
dura sori rẹ̀, ki nwọn ki o mã ta oróro si i
lori li orukọ Oluwa :
15 Adura igbagbọ́ yio si gbà olokunrùn
là, Oluwa yio si gbé e dide ; bi o ba si ṣepe
o ti dẹṣẹ, a o dari wọn jì i.
16 Ẹ jẹwọ ẹ̀ṣẹ nyin fun ara nyin, ki ẹ si
mã gbadura fun ara nyin, ki a le mu nyin
larada. Adura gbigbona olododo ti kì
itase ama ṣiṣẹ pipọ.
17 Enia oniru ìwa bi awa ni Elijah, o
gbadura gidigidi pe ki o máṣe rọ̀jo ? kò si
rọ̀jo si ilẹ niwọn ọdún mẹta on oṣù mẹfa.
18 O si tún gbadura, ọrun si tún rọ̀jo,
ilẹ si so eso rẹ̀ jade.
19 Ará, bi ẹnikẹni ninu nyin ba ṣìna
kuro ninu otitọ, ti ẹnikan si yi i pada ;
20 Ki on ki o mọ̀ pe, ẹniti o ba yi ẹlẹṣẹ
pada kuro ninu ìṣina rẹ̀, yio gbà ọkàn kan
là kuro ninu ikú, yio si bò ẹ̀ṣẹ pipọ mọlẹ.

Digitized by Google

EPISTELI IKINI TI

# PETERU,

FUN ENIA GBOGBO.

## ORI 1.

PETERU, Aposteli Jesu Kristi, si awọn alejò ti o fọ́nka kiri ni Pontu, Galatia, Kappadokia, Asia, ati ni Bitinia,

2 Ẹni ayanfẹ, gẹgẹ bi ìmọtẹlẹ Ọlọrun Baba, nipa isọdimimọ́ Ẹmí, si igbagbọ́ ati ibuwọ́n ẹ̀jẹ Jesu Kristi: Ore-ọfẹ si nyin, ati alafia, ki o ma bisi i.

3 Olubukún li Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, bi ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ̀, ẹniti o ti tún wa bí si ãye ireti nipa ajinde Jesu Kristi kuro ninu okú,

4 Si ilẹ-nini aidibajẹ, ati aili abawọn, ati eyi ti kì iṣá, ti a pamọ́ li ọrun fun nyin,

5 Ẹniti a pamọ́ nipa agbara Ọlọrun nipa igbagbọ́ si igbala, ti a mura lati fihàn nigba ikẹhin.

6 Ninu eyi ti ẹnyin nyọ̀ pipọ, ṣugbọn nisisiyi bi ẹnyin kò tilẹ le ṣaimáṣe ibinujẹ nigba diẹ kan nitori idanwò pipọ:

7 Ki idanwò igbagbọ́ nyin, ti o ni iye lori firi jù wura ti iparun lọ, bi o tilẹ ṣepe iná li a fi ndán a wò, ki a le bá a ninu iyìn, ati ọlá, ati ninu ogo nigba ifarahàn Jesu Kristi:

8 Ẹniti ẹnyin kò ri, ti ẹ nfẹ; bi ẹnyin kò tilẹ ri i nisisiyi, ṣugbọn ẹnyin ngbà a gbọ́, ẹnyin nyọ̀ ayọ̀ ti a kò le sọ, ti o si kún fun ogo:

9 Ẹnyin si ngbà opin igbagbọ́ nyin, ani igbala ọkàn nyin.

10 Ti igbala ti awọn woli bère, ti nwọn si wadi rẹ̀ gidigidi, awọn ẹniti o sọ ti ore-ọfẹ tẹlẹ ti mbọ̀ fun nyin:

11 Nwọn nwadi kini, tabi irú igba wo li Ẹmí Kristi ti o wà ninu wọn nsọ, nigbati o tète jẹri ìya Kristi, ati ogo ti yio tẹ̀le e lẹhin.

12 Awọn ẹniti a fihàn fun, pe kì iṣe fun awọn tikara wọn, bikoṣe fun awa ni nwọn nṣe iranṣẹ ohun wọnni, ti a ròhin fun nyin nisisiyi, lati ọdọ awọn ti o ti nwãsu ihinrere fun nyin pẹlu Ẹmí Mimọ́ ti a rán silẹ lati ọrun wá; ohun ti awọn angeli nfẹ bojuwò.

13 Nitorina ẹ di àmure ẹgbẹ nyin, ki ẹ si wà li airekọja, ki ẹ si mã reti are de opin dè ore-ọfẹ, ti a nmu bọ̀ fun nyin wá nigba ifarahàn Jesu Kristi;

14 Gẹgẹ bi awọn eleti ọmọ, li aifi ara nyin dáṣa bi ifẹkufẹ atijọ ninu aimọ̀ nyin:

15 Ṣugbọn bi ẹni ti o pè nyin ti jẹ mimọ́, bẹ̃ni ki ẹnyin ki o si jẹ mimọ́ ninu irú ìwa nyin gbogbo:

16 Nitori ti a kọwe rẹ̀ pe, Ẹ jẹ mimọ́; nitori ti emi jẹ mimọ́.

17 Bi ẹnyin ba si npè orukọ Baba, li aiṣe ojusaju enia, ẹniti o nṣe idajọ bi iṣẹ olukuluku ti ri, ẹ mã rìn ọjọ igba atipo nyin ni ìbẹru:

18 Niwọn bi ẹnyin ti mọ̀ pe, a kò fi ohun ti idibajẹ rà nyin pada, bi fadaka ati wura, kuro ninu ìwa nyin asan, lati ọwọdọwọ fi ìtan gbà lati ọdọ awọn baba wá:

19 Bikoṣe ẹ̀jẹ Kristi iyebiye, bi agutan ti kò li ẹ̀gan ti kò si li abawọn:

20 Ẹniti a ti yàn tẹlẹ nitõtọ ṣaju ipilẹṣẹ aiye, ṣugbọn ti o fi ara hàn nigba ikẹhin wọnyi nitori nyin,

21 Ẹniti a tipasẹ rẹ̀ gbà Ọlọrun gbọ́, ẹniti o jí i dide kuro ninu okú, ti o si fi ogo fun u; ki igbagbọ́ ati ireti nyin ki o le wà lọdọ Ọlọrun.

22 Bi ẹnyin ti wẹ̀ ọkàn nyin mọ́ ni igbagbọ́ otitọ nipa Ẹmí si ifẹ ará li aiṣẹ̀tan, ẹ fẹ ọmọnikeji nyin gidigidi pẹlu ọkàn funfun:

23 Bi ẹnyin ti di atúnbi, kì iṣe lati inu irú ti idibajẹ wá, bikoṣe ti aidibajẹ, nipa ọ̀rọ Ọlọrun ti o wà lãye ti yio si mã gbé ilẹ titi lai.

24 Nitoripe bi koriko ni gbogbo ara, ati gbogbo ogo enia bi itanná koriko. Koriko ama gbẹ, itanná rẹ̀ a si rẹ̀ silẹ:

25 Ṣugbọn ọ̀rọ Oluwa duro titi lai. Ọ̀rọ na yi si ni ihin-rere ti a wãsu fun nyin.

Digitized by Google

## ORI 2.

NITORINA ẹ fi arankàn gbogbo lelẹ li
apakan, ati ẹ̀tan gbogbo, ati agabage-
be, ati ilara, ati sisọ ọ̀rọ buburu gbogbo,
2 Bi ọmọ ọwọ titun, ki ẹ mã fẹ wàra ọ̀rọ
na ti kò li àbula, ki ẹnyin ki o le mã ti
ipasẹ rẹ̀ dàgba:
3 Bi o ba ṣepe ẹnyin ti tọ́ ọ wò pe, olore-
ọfẹ li Oluwa.
4 Ẹniti ẹnyin ntọ̀ bọ̀, bi ẹnipe si okuta
ãye, ti a ti ọwọ́ enia kọ̀ silẹ nitõtọ, ṣugbọn
ti a ti ọwọ́ Ọlọrun yàn, iyebiye,
5 Ẹnyin pẹlu, bi okuta ãye, ti a mọ ni
ile ẹmí, oriṣẹ-alufa mimọ́, lati mã ru ẹbọ
ẹmí, ti iṣe itẹwọgbà lọdọ Ọlọrun nipa Jesu
Kristi.
6 Nitorina bi o ti wà ninu iwe mimọ́
pẹlu pe, Kiyesi i, Mo fi pàtaki okuta igunle,
àṣayan, iyebiye, sọlẹ ni Sioni: ẹnikẹni ti o
ba si gbà a gbọ́ kì yio dãmu.
7 Nitorina fun ẹnyin ti o gbagbọ́, o ṣe
iyìn fun: ṣugbọn fun awọn ti iṣe alaigbọ-
ran, okuta ti awọn ọmọle kọ̀ silẹ, on na li
o si di pàtaki igunle,
8 Ati okuta idugbolu, on apata ikọsẹ̀ si
awọn ti o ndugbolu ọ̀rọ na, ti nwọn nṣe
alaigbọran: ninu eyiti a gbé yàn wọn si
pẹlu.
9 Ṣugbọn ẹnyin ni iran ti a yàn, ẹni-
oriṣẹ-olu-alufa, orilẹ-ède mimọ́, enia ọ̀tọ;
ki ẹnyin ki o le fi iyìn ẹniti o pè nyin jade
kuro ninu òkunkun sinu iyanu imọlẹ rẹ̀
hàn:
10 Nigba atijọ ẹniti kì iṣe enia, ṣugbọn
nisisiyi ti ẹnyin di enia Ọlọrun: ẹniti kò
ti ri ãnu gbà ri, ṣugbọn nisisiyi ti ẹnyin ri
ãnu gbà.
11 Olufẹ ọwọn, mo bẹ̀ nyin, bi alejò ati
bi èro, ẹ fà sẹhin kuro ninu ifẹkufẹ ara, ti
o mba ọkàn jagun;
12 Ki ìrin nyin ki o ṣe otitọ ninu awọn
Keferi; nipe, bi nwọn ti nsọ̀rọ si nyin bi
oluṣe buburu, nipa iṣẹ rere nyin, ti nwọn
o mã wò, ki nwọn ki o le mã yìn Ọlọrun
logo li ọjọ ìbẹwo.
13 Ẹ fi ara nyin balẹ fun gbogbo ìlana
enia nitoriti Oluwa: bi fun ọba ni, fun bi
ẹniti o bori gbogbo;
14 Tabi fun awọn bãlẹ, fun bi awọn ti a
ti ọdọ rẹ̀ rán nitori ati ṣẹ́ awọn oluṣe
buburu nìṣẹ, ati nitori iyìn awọn ti nṣe
rere.
15 Bẹ̃ sá ni ifẹ Ọlọrun, pe ni rere iṣe ki
ẹnyin ki o le pa òpe awọn enia wère li ẹnu
mọ́:
16 Bi omnira enia, ati li ailò omnira fun
iboju arankàn, bikoṣe bi awọn ẹrú Ọlọrun.
17 Ẹ buyìn fun gbogbo enia. Ẹ fẹ awọn
ará. Ẹ bẹru Ọlọrun. Ẹ bọ̀wọ fun ọba.
18 Ẹnyin ọmọ-ọdọ, ẹ foribalẹ fun awọn
oluwa nyin pẹlu ìbẹru gbogbo; ki iṣe fun
kìki awọn ẹni rere ati pẹlẹ, ṣugbọn fun
awọn onrorò pẹlu.
19 Nitoripe eyi ni ore-ọfẹ, nitori ọkàn
sipa Ọlọrun bi enia ba pa ìya mọra, ti o
njìya lasan.
20 Nitori ogo kili o wà, nigbati a nlù
nyin nitori ẹ̀ṣẹ nyin, bi ẹnyin fi sũru gbà
a? ṣugbọn nigbati ẹnyin ba nṣe rere, bi
ẹnyin ba jìya nitori na, ti ẹnyin ba si fi
sũru gbà a, eyiyi ni itẹwọgbà lọdọ Ọlọrun.
21 Nitoripe inu eyi li a pè nyin si:
nitoriti Kristi jìya fun wa pẹlu, o làna silẹ
fun wa, ki ẹnyin ki o le mã tọ̀ ipasẹ rẹ̀:
22 Ẹniti kò ṣẹ̀ ẹ̀ṣẹkẹṣẹ, ti a kò si ri are-
kereke li ẹnu rẹ̀:
23 Ẹni, nigbati nwọn nkẹgan rẹ̀, ti kò
si pada kẹgan; nigbati o jìya, ẹniti kò si
kìlọ; ṣugbọn o fi ọran rẹ̀ le ẹniti iṣe idajọ
ododo lọwọ:
24 Ẹniti on tikararẹ̀ fi ara rẹ̀ rù ẹ̀ṣẹ wa
de ori igi, nipe, awa ti a ti di okú si ẹ̀ṣẹ,
ki a le di ãye si ododo: nipa ìna ẹniti a
mu nyin larada.
25 Nitori ẹnyin ti dabi agutan ti o nṣìna;
ṣugbọn nisisiyi ẹnyin npada si ọdọ Oluṣọ-
agutan, ati Biṣopu ọkàn nyin.

## ORI 3.

BẸ̃ gẹgẹ, ẹnyin aya, ẹ foribalẹ fun awọn
ọkọ nyin; bi o ba ṣepe awọn kan wà
ti kò gbà ọ̀rọ na gbọ́, nipa ìrin awọn aya
wọn ki a lè fà wọn li aifi ti ọ̀rọ na ṣe;
2 Nigbati nwọn ba nwò ìrin daradara
nyin ti on ti ẹ̀ru.
3 Ọṣọ́ ẹniti ki a máṣe jẹ ki o ṣe ọṣọ́ ode
ni ti irun didì, ati ni ti iṣọṣọ́ wura, tabi ni
ti aṣọ wiwọ̀;
4 Bikoṣe ti enia nì ti o lumọ́ li ọkàn,
ninu eyi ti ki idibajẹ, ọṣọ́ ẹmí tutù ati pẹlẹ,
li oju Ọlọrun eyi ti iṣe iyebiye.
5 Nitori bi irú eyi li awọn obirin mimọ́
igbãni pẹlu, ti nwọn gbẹkẹlẹ Ọlọrun, fi ṣe
ara wọn li ọṣọ́, nwọn ama wà ni iforibalẹ
fun awọn ọkọ wọn:
6 Gẹgẹ bi Sara ti gbà Abrahamu gbọ́, ti
o npè e li oluwa: ọmọbirin ẹniti ẹnyin iṣe,
niwọn bi ẹ ba ti nṣe rere si, ti ẹ kò si fi
ipaiya bẹrukẹru.
7 Ẹnyin ọkọ pẹlu, ẹ mã ba wọn gbé
gẹgẹ bi ìmọ, ẹ mã fi iyìn fun aya, bi ohun-

Digitized by Google

èlo ti kò lera, ati bi ẹgbẹ arole ore-ọfẹ ìye; ki adura nyin ki o máṣe ni ìdena.

8 Lakotan, ki gbogbo nyin ṣe oninu kan, ki ẹ si mã ṣe iyọ́nu si ọmọnikeji, ẹ mã fẹni bi ará, ẹ ṣe iyọ́nu, ẹ ṣore:

9 Ẹ máṣe fi buburu san buburu, tabi fi ẽbú san ẽbú; ṣugbọn kàka bẹ̃, ẹ fi ibukún san; ki ẹ ma mọ̀ pe eyini li a pè nyin si, ki ẹnyin ki o le jogún ibukún.

10 Nitori ẹniti o ba fẹ ìye, ti o si nfẹ ri ọjọ rere, jẹ ki o pa ahọn rẹ̀ mọ́ kuro ninu buburu, ati ète rẹ̀ ki o má sọ̀rọ ẹ̀tan:

11 Ki o yapa ibi silẹ, ki o si mã ṣe rere; jẹ ki o ma wá alafia, ki o si mã lepa rẹ̀.

12 Nitori oju Oluwa mbẹ lara awọn olododo, etí rẹ̀ si ṣí si adura wọn: ṣugbọn oju Oluwa korò si awọn ti nṣe buburu.

13 Tani yio si ṣe buburu si nyin, bi ẹnyin ba ṣe ọmọ-ẹhin ohun ti iṣe rere?

14 Ṣugbọn bi ẹnyin ba jìya nitori ododo, alafia ni: ẹ máṣe fòya ẹ̀ru wọn, ki ẹ má si ṣe kọnnu;

15 Ṣugbọn ẹ bọ̀wọ fun Kristi Oluwa li àiya nyin: ki ẹ si mura nigbagbogbo lati dá olukuluku enia lohùn pẹlu ọkàn tutù ati ìbẹru, ẹniti o bère idi ireti ti o wà ninu nyin:

16 Bi ẹniti o li ọkàn rere; nipe, bi nwọn nsọ̀rọ nyin ni buburu, bi ẹniti nṣe ibi, ki oju ki o tì awọn ti o nfi eke sọ̀rọ buburu si ìrin rere nyin ninu Kristi.

17 O sá dara bi ifẹ Ọlọrun ba ri bẹ̃, ki ẹnyin ki o jìya ni rere iṣe, jù ni buburu iṣe lọ.

18 Nitori ti Kristi pẹlu jìya lẹ̃kan nitori ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ fun awọn alaiṣõtọ, ki o le mu wa de ọdọ Ọlọrun, ẹniti a pa ni ikú ara, ṣugbọn ẹniti a sọ di ãye nipa Ẹmí:

19 Nipa eyi ti o si fi lọ ti o si wasu fun awọn ẹmí ti mbẹ ninu tubu;

20 Nigbakan awọn ẹniti o ṣe alaigbọran, ni sã kan ti lãkari Ọlọrun duro pẹ titi nigba ọjọ Noa, nigbati nwọn fi nkàn ọkọ̀ (arki) lọwọ, ninu eyi ti enia diẹ là, eyini ni ọkàn mẹjọ nipa omi.

21 Irú apẹrẹ bẹ̃ gẹgẹ ni baptismu si fi ngbà wa là nisisiyi, ki iṣe ìwẹ ẽri ti ara nù, bikoṣe idahùn ọkàn rere sipa Ọlọrun, nipa ajinde Jesu Kristi:

22 Ẹniti o ti lọ si ọrun, ti o si mbẹ li ọwọ́ ọtún Ọlọrun; ori awọn angeli ati ti awọn ọlọlá ati alagbara li a fi mbalẹ fun u.

## ORI 4.

NJẸ bi Kristi ti jìya fun wa nipa ara, irú inu bẹ̃ gẹgẹ ni ki ẹ fi mura: nitori ẹniti o ba ti jìya nipa ti ara o simi kuro lọwọ ẹ̀ṣẹ;

2 Ki on ki o máṣe fi igba aiye rẹ̀ iyokù wà ninu ara mọ́ si ifẹkufẹ enia, bikoṣe si ifẹ Ọlọrun.

3 Nitori igba aiye wa ti o kọja, ki o to fun wa, ni ti a ti nṣiṣẹ ifẹ awọn Keferi, nigbati awa nrìn ni wọ̀bia, ifẹkufẹ, ọti-waini amuju, irede oru, ọti ajọmupọ̀, ati ninu oriṣa sisìn ti o burujù:

4 Ninu eyi ti nwọn rò pe, o ṣe àjeji si wọn ti ẹnyin kò ba wọn dù u to irú aṣejù ariwo na, nwọn nsọ̀rọ buburu si nyin:

5 Awọn ẹniti yio jihin fun ẹniti o mura ati ṣe idajọ ãye on okú.

6 Nitori eyi na li a sá ṣe wasu ihin-rere fun awọn okú pẹlu, ki a le ṣe idajọ wọn bi enia nipa ti ara, ṣugbọn ki nwọn ki o le yè si Ọlọrun nipa ẹmí.

7 Ṣugbọn opin ohun gbogbo kù si dẹ̀dẹ: nitorina ki ẹnyin ki o wà li airekọja, ki ẹ si mã ṣọra si i pẹlu adura.

8 Ati jù gbogbo rẹ̀ lọ, ki ẹ ni ifẹ ti o gbóna ninu ara nyin: nitori ifẹ ni yio bò ọ̀pọlọpọ ẹ̀ṣẹ mọlẹ.

9 Ẹ mã ṣe ara nyin li alejò li aikùn sinu.

10 Bi olukuluku ti ri ẹ̀bun gbà, bẹ̃ni ki ẹ ṣe iranṣẹ ọkanna ekini si ekeji, bi iriju rere ti onirũru ore-ọfẹ Ọlọrun.

11 Bi ẹnikan ba nsọ̀rọ, ki o mã sọ bi ọ̀rọ Ọlọrun; bi ẹnikẹni ba nṣe iṣẹ iranṣẹ, ki o ṣe e bi agbara ti Ọlọrun fifun u: ki a le mã yìn Ọlọrun logo li ohun gbogbo nipa Jesu Kristi, ẹniti ìyìn ati ijọba wà fun lai ati lailai. Amin.

12 Olufẹ ẹ máṣe rò ti idanwò iná ti mbọ̀wa idán nyin wò si ohun àjeji, bi ẹnipe ohun àjeji kan li o bá nyin:

13 Ṣugbọn ẹ mã yọ̀, niwọn bi ẹnyin ti jẹ alabapin ninu ìya Kristi; pe nigbati a ba fi ogo rẹ̀ hàn, ẹnyin o yọ̀ ayọ̀ pipọ.

14 Bi a ba ngàn nyin nitori orukọ Kristi, alafia ni; nitori ẹmí ogo ati ti Ọlọrun bà le nyin: nipa ti wọn nwọn nsọ̀rọ rẹ̀ ni ibi, ṣugbọn nipa ti nyin a nyìn i logo.

15 Ṣugbọn ẹ má jẹ ki ẹnikẹni ninu nyin ki o jìya bi apania, tabi bi olè, tabi bi oluṣe-buburu, tabi bi olofófo li ọ̀ran ẹlomiran.

16 Ṣugbọn bi o ba jìya bi Kristiani, ki oju ki o máṣe tì i; ṣugbọn ki o kuku yìn Ọlọrun logo nitori eyi.

17 Nitori ti ìgba na de, ti idajọ yio bẹ̀rẹ lati ile Ọlọrun wá: bi o ba si tète ti ọdọ wa bẹ̀rẹ, opin awọn ti kò gbà ihin-rere Ọlọrun gbọ́ yio ha ti ri?

Digitized by Google

18 Bi o ba ṣepe agbara káka li olododo
yio fi là a, nibo li ẹni buburu on ẹlẹṣẹ yio
gbé yọju si?
19 Nitorina ẹ jẹ ki awọn ti njìya gẹgẹ
bi ifẹ Ọlọrun, ki o fi ipamọ́ ọkàn wọn le e
lọwọ ni rere iṣe, bi ẹnipe fun Ẹlẹda olõtọ.

## ORI 5.

AWỌN alàgba ti o wà ninu nyin ni mo
bẹ̀, emi ẹniti iṣe alàgba pẹlu, ati ẹlẹri
ìya Kristi, ati olubapin ninu ogo ti a o fi
hàn:
2 Ẹ mã bọ́ agbo agutan Ọlọrun ti o wà
ninu nyin, ẹ mã bojuto o, kì iṣe ti ifi iyanju
ṣe, bikoṣe ti ifẹ inu didùn; ki iṣe nitori
èrekere ijẹ, bikoṣe ni ti inu rere ti o ti
mura tẹlẹ;
3 Bẹ̃ni ki ẹnyin ki o máṣe bi oluwa lori
ilẹ-nini Ọlọrun, bikoṣe ki ẹ mã ṣe apẹrẹ
fun agbo.
4 Nigbati olori Oluṣọ-agutan ba si fi
ara hàn, ẹnyin o gbà ade ogo ti kì iṣá.
5 Bẹ̃ pẹlu, ẹnyin ipẽrẹ, ẹ foribalẹ fun
awọn àgba. Nitotọ gbogbo nyin ẹ mã
foribalẹ fun ara nyin, ki a si fi irẹlẹ wọ̀
nyin: nitori Ọlọrun kọjùjasi awọn onirera,
ṣugbọn o fi ore-ọfẹ fun awọn onirẹlẹ ọkàn.
6 Nitorina ẹ rẹ̀ ara nyin silẹ labẹ ọwọ́
agbara Ọlọrun, ki on ki o si gbé nyin leke
li akokò:
7 Ẹ mã kó gbogbo aniyan nyin le e
lọwọ; nitori ti o nṣe aniyan nyin.
8 Ẹ mã wà li airekọja, ẹ mã ṣọra; nitori
Èṣu, ọtá nyin, bi kiniun ti nke ramuramu,
o nrìn ká kiri, o nwá ẹniti yio pajẹ kiri:
9 Ẹniti ki ẹnyin ki o kọjùjasi girigiri
ninu igbagbọ́, ki ẹnyin ki o mọ̀ pe ipọnju
na ti ṣẹ ninu awọn arakọnrin nyin ti o wà
li aiye.
10 Ṣugbọn Ọlọrun ore-ọfẹ gbogbo, ti o
pè wa sinu ogo rẹ̀ ti kò nipẹkun ninu
Kristi Jesu, nigbati ẹnyin ba jìya nigba diẹ,
ki o ṣe nyin li aṣepé, ki o fi ẹsẹ nyin mulẹ,
ki o fun nyin li agbara, ki o fi idi nyin
kalẹ.
11 On li ogo ati agbara mbẹ fun lai ati
lailai. Amin.
12 Lati ọwọ́ Silfanu, arakọnrin olõtọ si
nyin, bi emi ti rò, mo kọwe diẹ yi, emi
ngbà nyin niyanju, emi si njẹri pe, eyiyi li
otitọ ore-ọfẹ Ọlọrun, ninu eyi ti ẹnyin gbé
duro.
13 Ijọ ti mbẹ ni Babiloni, ti a yàn pẹlu
nyin, kí nyin; ati Marku ọmọ mi.
14 Ifẹnukoni ifẹ ni ki ẹ fi kí ara nyin.
Ki alafia ki o wà pẹlu gbogbo ẹnyin ti o
mbẹ ninu Kristi Jesu. Amin.

---

EPISTELI EKEJI TI

# PETERU,

FUN ENIA GBOGBO.

## ORI 1.

SIMONI PETERU, iranṣẹ ati Aposteli
Jesu Kristi, si awọn ti o ti gbà irú
iyebiye igbagbọ́ na pẹlu wa, nipa ododo
Ọlọrun ati Jesu Kristi Olugbala wa:
2 Ki ore-ọfẹ ati alafia ki o mã bisi i fun
nyin nipa ìmọ Ọlọrun, ati ti Jesu Oluwa
wa,
3 Gẹgẹ bi agbara rẹ̀ ọrun ti fun wa li
ohun gbogbo ti iṣe ti ìye ati ti ìwabi-Ọlọ-
run, nipa ìmọ ẹniti o ti pè wa si ogo ati si
ìwa-ọrun:
4 Nipa eyi ti a nfi ileri nlanla ati iyebiye
fun wa: pe nipa wọnyi ni ki ẹnyin ki o le
ṣe alabapin ninu ìwa ẹda ọrun, ni ti ẹnyin
nyọ kuro ninu ibajẹ ti o wà li aiye nipa ifẹ-
kufẹ.
5 Ati pẹlu eyi, ẹ mã ṣe aisimi gbogbo, ẹ
fi ìwa-ọrun kún igbagbọ́ nyin; ati ìmọ kún
ìwa-ọrun;
6 Ati airekọja kún ìmọ; ati sũru kún
airekọja; ati ìwabi-Ọlọrun kún sũru;
7 Ati ifẹ ọmọnikeji kún ìwabi-Ọlọrun;
ati ifẹni kún ifẹ ọmọnikeji.
8 Nitori bi nkan wọnyi ba mbẹ ninu

Digitized by Google

nyin, ti o si pọ̀, nwọn kì yio mu nyin di
aṣálẹ tabi alaileso ni ìmọ Jesu Kristi Oluwa
wa.
9 Ṣugbọn ẹniti o ba ṣe alaini nkan wọnyi,
o fọju, kò le riran li òkere, o si ti gbagbé
pe a ti wẹ̀ on nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀ lailai.
10 Nitorina, ará, ẹ kuku mã ṣe aisimi,
lati sọ ìpe ati ìyan nyin di dajudaju: nitori
bi ẹnyin ba nṣe nkan wọnyi, ẹnyin kì yio
ṣubu titi lai:
11 Nitori bẽli a o ṣe ìlana silẹ fun nyin
pipọpipọ si ijọba ainipẹkun ti Jesu Kristi
Oluwa ati Olugbala wa.
12 Nitorina emi kì yio jafara ati mã rán
nyin leti nkan wọnyi nigbagbogbo, bi
ẹnyin tilẹ ti mọ̀ wọn, ti ẹsẹ nyin si mulẹ
ninu otitọ isisiyi.
13 Emi si rò pe o yẹ, niwọn bi emi ti
mbẹ ninu agọ́ yi, lati mã fi iranti rú nyin
soke;
14 Ni bi emi ti mọ̀ pe, nisisiyi li emi o
bọ agọ́ mi yi silẹ, gẹgẹ bi Jesu Kristi Oluwa
wa ti fihàn mi.
15 Ati pẹlu, emi o si ma ṣãpọn ki ẹnyin
ki o le ma ranti nkan wọnyi nigbagbogbo
lẹhin ikú mi.
16 Nitori awa kò tọ̀ ìtan asan ti a fi
ọgbọ́n-kọgbọn là silẹ lẹhin, nigbati awa
nfi agbara ati wíwa Jesu Kristi Oluwa wa
hàn nyin, ṣugbọn awa ni iṣe ẹlẹri ojuri ti
ọlánla rẹ̀.
17 Nitoriti o gbà ọlá on ogo lọwọ Ọlọrun
Baba, nigbati irú ohùn nì fọ̀ si i lati ogo
nla na wá pe, Eyi li ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti
inu mi dùn si jọjọ.
18 Ati ohùn yi ti o ti ọrun wá awa gbọ́,
nigbati awa mbẹ pẹlu rẹ̀ lori òke mimọ́ na.
19 Awa si ni ọ̀rọ asọtẹlẹ ti o daniloju jù
bẽ lọ; ninu eyi ti o yẹ gidigidi lati fiyesi,
bi imọlẹ ti o mọ́ ni ibi òkunkun, titi afẹ-
mọ́jumọ, ti irawọ owurọ̀ si fi là li àiya nyin:
20 Ki ẹ tète mọ̀ eyi na, pe kò si ọkan
ninu asọtẹlẹ inu iwe mimọ́ ti o ni itumọ̀
ìkọkọ.
21 Nitori asọtẹlẹ kò ti ipa ifẹ enia wá
nigbãni: ṣugbọn awọn enia mimọ́ Ọlọrun
nwi bi a ti nsọ si wọn ninu wá lati ọwọ́
Ẹmí Mimọ́.

ORI 2.

ṢUGBỌN awọn woli eke wà ninu awọn
enia na pẹlu, gẹgẹ bi awọn olukọ́ni eke
yio si wà ninu nyin, awọn ẹniti yio ti abẹlẹ
mu adámọ egbé wọ̀ inu nyin wá, nwọn o
tilẹ ma sẹ́ Oluwa ti o rà wọn, nwọn o si mu
iparun yara wá sori ara wọn.
2 Ọ̀pọ enia ni yio si mã tọ̀pa egbé wọn;
nitori idi ẹniti a o fi mã sọ̀rọ buburu si ọ̀na
otitọ.
3 Ati nipasẹ ojukòkoro ni nwọn o fi mã
fi ọ̀rọ ẹ̀tan fi nyin ṣe ọjà tità: idajọ ẹniti
kò duro pẹ titi mọ́ nisisiyi, ati ẹbi awọn
ẹniti kò tõgbe.
4 Nitoripe bi Ọlọrun kò ti dá awọn
angeli ti o ti ṣẹ̀ si, ṣugbọn ti o tì wọn lọ si
isalẹ ọrun-apadi, ti o si fi wọn sinu ẹ̀wọn
òkunkun lati pa wọn mọ́ dè ọjọ idajọ;
5 Ti kò si dá aiye igbãni si, ṣugbọn o
yọ Noa pẹlu enia meje, oniwãsu ododo,
nigbati o tú omi dà si aiye awọn enia bu-
buru;
6 Ti o si sọ awọn ilu Sodomu on Gomorra
di ẽru, nigbati o fi ifọ́ afọbajẹ dá wọn lẹbi,
ti o fi wọn ṣe apẹrẹ fun awọn ti yio ma hù
ìwa buburu nigbẹhin;
7 O si gbà Lotu olõtọ là, ti inu rẹ̀ bajẹ
si ìwa-ẽri awọn enia buburu:
8 (Nitori ọkọnrin olododo nì bi o ti ba
wọn joko, ti o ngbọ́ ti o si nri ìwa buburu
wọn, ọkàn otitọ rẹ̀ bajẹ li ojojumọ́:)
9 Oluwa mọ̀ bi on o ti yọ awọn ẹni ìwa-
bi-Ọlọrun kuro ninu ipọnju, on ati pa
awọn alaiṣõtọ mọ́ dè ọjọ idajọ lati ṣẹ́ niṣẹ:
10 Ṣugbọn jù gbogbo rẹ̀ lọ awọn ti ntọ̀
ifẹ ara lẹhin ni ifẹkufẹ ẽri, ti nwọn si ngàn
ijoye. Alagidi, aṣe-tinu ẹni, nwọn kò bẹ̀ru
ati mã sọ̀rọ buburu si awọn oloye.
11 Nigbati awọn angeli, ti o pọ̀ li agbara
ati ni ipá, kò ti mu ọ̀rọ ẹ̀gan si wọn wá
siwaju Oluwa.
12 Ṣugbọn awọn wọnyi, bi ẹranko igbẹ́
nipa ti ara, ti a dá lati ma mu pa, nwọn
nsọ̀rọ buburu si ohun ti kò yé wọn; nwọn
o si ṣegbé raurau ninu ibajẹ ara wọn;
13 Nwọn o si jẹ ère aiṣododo, bi awọn ti o
kà a si aiye ijẹ lati mã jẹ adùn aiye li ọsán.
Abawọn on àbuku ni nwọn, nigbati nwọn
nfi ẹ̀tan ara wọn jẹ aiye, nigbati nwọn ba
mbá nyin jẹun;
14 Oloju ti o kún fun panṣaga, ti kò si
le dẹkun ẹ̀ṣẹ idá; ẹniti ntàn ọkàn ti kò fi
ẹsẹ mulẹ jẹ: àiya ti nwọn ti nfi ṣe iṣẹ
ojukòkoro; awọn ọmọ egún:
15 Awọn ti o ti kọ̀ ọ̀na otitọ silẹ, ti nwọn
yapa, nwọn ntọ̀pa ọ̀na Balaamu ọmọ Boso-
ru, ẹniti o fẹràn ère aiṣododo;
16 Ẹniti a si bawi nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀: odi kẹ-
tẹkẹtẹ nfi ohùn enia sọ̀rọ, o kọ̀ agidi woli
na.
17 Awọn wọnyi ni kanga ti kò li omi,
ikũku ti ẹfũfu ngbá kiri; awọn ẹniti a pa
òkunkun biribiri mọ́ de titi lai.

Digitized by Google

18 Nitori igbati nwọn ba nsọ̀rọ ihalẹ
asan nla, nipa ifẹ ara, ati aṣeju, nwọn ama
tàn awọn ti o ti bọ́ tan lọwọ awọn ti o wà li
ọ̀na ṣiṣì.
19 Nigbati nwọn ba nṣe ileri omnira fun
wọn, ẹrú idibajẹ li awọn tikara wọn: nitori
ọwọ́ ẹniti ati ṣẹgun ẹni, ati ọwọ́ oluwarẹ̀ na
li a si ti sọ ọ di ondè.
20 Nitori igbẹhin ti nwọn ba ti yọ tan
kuro ninu ẽri aiye, nipa mimọ̀ Jesu Kristi
Oluwa ati Olugbala wa, bi nwọn ba si tun
fi ara wọn kọ́ ninu rẹ̀, ti a si ṣẹgun wọn,
igbẹhin wọn buru jù ti iṣaju lọ.
21 Nitori o san fun wọn, ki nwọn ki o
má kuku mọ̀ ọ̀na ododo, jù igbẹhin ti nwọn
mọ̀ ọ tan, ki nwọn ki o yipada kuro ninu
ofin mimọ́ ti a fifun wọn.
22 Ṣugbọn o ṣẹ si wọn bi owe otitọ nì,
Ajá tún pada si ẽbì ara rẹ̀; ati abo ẹlẹdẹ ti
a wẹ̀ tan, pada sinu àfọ rẹ̀ ninu ẹrẹ̀.

## ORI 3.

OLUFẸ, iwe keji yi ni mo kọ si nyin ni-
sisiyi; ninu mejeji na li emi nrú inu
nyin funfun soke nipa iranti:
2 Ki ẹnyin ki o le mã ranti ọ̀rọ ti a ti
ẹnu awọn woli mimọ́ sọ ṣaju, ati ofin awa
ti iṣe aposteli Oluwa ati Olugbala wa:
3 Ki ẹ tète mọ̀ eyi na pe, awọn ẹlẹgan
yio de nigba ọjọ ikẹhin, nwọn o mã rìn
nipa ifẹ ara wọn,
4 Nwọn o si mã wipe, Nibo ni ileri wí-
wa rẹ̀ gbé wà? nigbati awọn baba ti sùn,
bakanna li ohun gbogbo sá ri lati ìgba ọjọ
ìwa.
5 Eyiyi ni nwọn nfẹ fi mimọ̀ ṣe aimọ̀, pe
nipa ọ̀rọ Ọlọrun li awọn ọrun ti wà li atijọ,
ati ti ilẹ yọri jade ninu omi, ti o si duro
ninu omi:
6 Nipa eyi ti aiye ti o wà nigbãni, ti o
rì ninu omi, o parun:
7 Ṣugbọn awọn ọrun ati aiye, ti mbẹ ni-
sisiyi, nipa ọ̀rọ na li a fi ṣura, ti a si pa
wọn mọ́ dè iná ọjọ idajọ, ati dè ọjọ egbé
awọn enia buburu.
8 Ṣugbọn, olufẹ, ki ẹ máṣe alaimọ̀ nkan
ṣoṣo yi, pe ọjọ kan lọdọ Oluwa bi ẹgbẹ̀run
ọdún li o ri, ati ẹgbẹ̀run ọdún bi ọjọ
kan.
9 Oluwa kò jafara nipa ileri rẹ̀, bi awọn
ẹlomiran iti kà ijafara; ṣugbọn o mu sũru
sipa ọdọ wa, niti ti kò fẹ ki ẹnikẹni ki o
ṣegbé, bikoṣe ki gbogbo enia ki o wá si
ironupiwada.
10 Ṣugbọn ọjọ Oluwa mbọ̀wa bi olè li
oru; ninu eyi ti awọn ọrun yio fò lọ ti
awọn ti ariwo nla, ati awọn ori-ẹ̀ya rẹ̀ yio
si ti inu oru gbigbona di yíyọ, ilẹ pẹlu ati
iṣẹ ti o wà ninu rẹ̀ yio si jóna lulu.
11 Njẹ bi nkan wọnyi gbogbo yio ti yọ́
nì, irú enia bawo li ẹnyin iba jẹ ninu ìwa
mimọ́ gbogbo ati ìwabi-Ọlọrun,
12 Ti ẹnyin nwoye, ti ẹnyin si nmura
giri dè wíwa ọjọ Ọlọrun, ninu eyi ti awọn
ọrun yio gbiná, ti nwọn o di yíyọ, ati ori-
ẹ̀ya rẹ̀ yio si ti inu oru gbigbona di yíyọ?
13 Ṣugbọn gẹgẹ bi ileri rẹ̀, awa nwoye
awọn ọrun titun ati aiye titun, nibiti
ododo gbé wà.
14 Nitorina, olufẹ, bi ẹnyin ti nwoye irú
nkan wọnni, ẹ mura giri, ki a le bá nyin
ni tirẹ̀ li alafia, li ailabawọn, ati li ailà-
buku.
15 Ki ẹ si ma kà a si pe, sũru Oluwa wa
igbala ni; ati bi Paulu pẹlu, arakọnrin
olufẹ wa, ti kọwe si nyin, gẹgẹ bi ọgbọ́n ti
a fifun u;
16 Ati pẹlu ninu iwe rẹ̀ gbogbo, o nsọ̀rọ
nkan wọnyi; ninu eyi ti ohun miran ti o
ṣoro imọ̀ gbé wà, ti awọn ọ̀pe ati awọn
alaiduro nibikan nlọ́, bi nwọn ti nṣe iwe
mimọ́ miran, si iparun ara wọn.
17 Nitorina ẹnyin olufẹ, bi ẹnyin ti mọ̀
nkan wọnyi tẹlẹ, ẹ mã kiyesara, nitori ki a
má ba fi ìṣina awọn enia buburu fà nyin lọ,
ki ẹ má ba ṣubu kuro ni iduro nyin ṣinṣin.
18 Ṣugbọn ẹ mã dàgba ninu ore-ọfẹ, ati
ninu ìmọ Jesu Kristi Oluwa ati Olugbala
wa. On li ogo wà fun ati nisisiyi ati titi
lai. Amin.

Digitized by Google

EPISTELI IKINI TI

# JOHANNU,

## FUN ENIA GBOGBO.

### ORI 1.

EYITI o ti wà li àtetekọṣe, ti awa ti gbọ́,
ti awa ti fi oju wa ri, ti awa si ti tẹ-
jumọ wò, ti ọwọ́ wa si dìmu, niti Ọrọ ìye ;
2 (Nitori ìye ti farahàn, awa si ri i, awa
si jẹri, awa si sọ ìye ainipẹkun na fun nyin,
ti o ti mbẹ pẹlu Baba, ti o si farahàn fun
wa ;)
3 Eyiti awa ti ri, ti awa si ti gbọ́ li awa
nsọ fun nyin, ki ẹnyin pẹlu ki o le ni ìda-
pọ pẹlu wa : ati nitõtọ ìdapọ wa mbẹ pẹlu
Baba, ati pẹlu Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀.
4 Nkan wọnyi li awa kọwe si nyin, ki
ayọ̀ nyin ki o le kún.
5 Njẹ eyi ni ọ̀rọ ti awa ti gbọ́ lọdọ rẹ̀, ti
awa si sọ fun nyin, pe imọlẹ li Ọlọrun, ati
pe òkunkun kò si lara rẹ̀ rara.
6 Bi awa ba wipe awa ní ìdapọ pẹlu rẹ̀,
ti awa si nrìn li òkunkun, awa nṣeke, awa
kò si ṣe otitọ :
7 Ṣugbọn bi awa ba nrìn ninu imọlẹ,
bi on ti mbẹ ninu imọlẹ, awa ní ìdapọ
pẹlu ara wa, ati ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ ni
nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa gbogbo.
8 Bi awa ba wipe awa kò li ẹ̀ṣẹ, awa tàn
ara wa jẹ, otitọ kò si si ninu wa.
9 Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olo-
dodo li on lati dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, ati lati
wẹ̀ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo.
10 Bi awa ba wipe awa kò ṣẹ̀, awa mu u
li eke, ọ̀rọ rẹ̀ kò si si ninu wa.

### ORI 2.

ENYIN ọmọde mi, iwe nkan wọnyi ni
mo kọ si nyin, ki ẹ máṣe ṣẹ̀. Bi ẹni-
kẹni ba ṣẹ̀, awa ni alagbawi kan lọdọ Baba,
Jesu Kristi olododo :
2 On si ni ètutu fun ẹ̀ṣẹ wa : kì si iṣe
kìki ti wa, ṣugbọn fun ẹ̀ṣẹ gbogbo araiye
pẹlu.
3 Nipa eyi li awa si mọ̀ pe awa mọ̀ ọ, bi
awa ba npa ofin rẹ̀ mọ́.
4 Ẹniti o ba wipe, emi mọ̀ ọ, ti kò si pa
ofin rẹ̀ mọ́, eleke ni, otitọ kò si si ninu rẹ̀.
5 Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba pa ọ̀rọ rẹ̀ mọ́,
lara rẹ̀ li a gbé mu ifẹ Ọlọrun pé nitõtọ ;
nipa eyi li awa mọ̀ pe awa mbẹ ninu rẹ̀.
6 Ẹniti o ba wipe on ngbé inu rẹ̀, on na
si yẹ lati mã rìn bẹ̃ pẹlu, gẹgẹ bi on ti
nrìn.
7 Ẹnyin ará, emi kò kọwe ofin titun si
nyin, bikoṣe ofin atijọ ti ẹnyin ti ni li àte-
tekọṣe. Ofin atijọ ni ọ̀rọ ti ẹnyin ti gbọ́ li
àtetekọṣe.
8 Ẹwẹ, ofin titun kan ni mo kọwe si
nyin, ohun ti iṣe otitọ ninu rẹ̀ ati ninu
nyin : nitoriti òkunkun ti kọja, imọlẹ
otitọ si ntàn nisisiyi.
9 Ẹniti o ba wipe on mbẹ ninu imọlẹ,
ti o si korira arakọnrin rẹ̀, o mbẹ ninu
òkunkun titi fi di isisiyi.
10 Ẹniti a ba fẹ arakọnrin rẹ̀ o duro
ninu imọlẹ, kò si si ohun ikọsẹ̀ ninu rẹ̀.
11 Ṣugbọn ẹniti o ba korira arakọnrin
rẹ̀ o mbẹ ninu òkunkun, o si nrìn ninu
òkunkun, kò si mọ̀ ibi ti on nrè, nitoriti
òkunkun ti ṣú u li oju.
12 Emi kọwe si nyin, ẹnyin ọmọde, ni-
tori ti a dari ẹ̀ṣẹ nyin jì nyin nitori orukọ
rẹ̀.
13 Emi kọwe si nyin, ẹnyin baba, ni-
tori ti ẹnyin ti mọ̀ on, ẹniti o wà lati igba
àtetekọṣe. Emi kọwe si nyin, ẹnyin ọdọ-
mọkọnrin, nitori ti ẹnyin ti ṣẹgun ẹni bu-
buru nì. Emi kọwe si nyin, ẹnyin ọmọde,
nitori ti ẹnyin ti mọ̀ Baba.
14 Emi ti kọwe si nyin, ẹnyin baba, ni-
tori ti ẹnyin ti mọ̀ on, ẹniti o wà lati igba
àtekekọṣe. Emi ti kọwe si nyin, ẹnyin
ọdọmọkọnrin, nitori ti ẹnyin li agbara, ti
ọ̀rọ Ọlọrun si duro ninu nyin, ti ẹ si ṣẹgun
ẹni buburu nì.
15 Ẹ máṣe fẹ aiye, tabi ohun ti mbẹ
ninu aiye. Bi ẹnikẹni ba fẹ aiye, ifẹ ti
Baba kò si ninu rẹ̀.
16 Nitori ohun gbogbo ti mbẹ li aiye,

Digitized by Google

ifẹkufẹ ara, ati ifẹkufẹ oju, ati irera aiye,
kò si ni ti Baba, bikoṣe ni ti aiye.
17 Aiye si nkọja lọ, ati ifẹkufẹ rẹ̀: ṣu-
gbọn ẹniti o ba nṣe ifẹ Ọlọrun ni yio duro
lailai.
18 Ẹnyin ọmọde, igba ikẹhin li eyi: bi
ẹnyin si ti gbọ́ pe Aṣodisi-Kristi mbọ̀wa,
ani nisisiyi Aṣodisi Kristi pupọ̀ ni mbẹ;
nipa eyiti awa fi mọ̀ pe igba ikẹhin li eyi.
19 Nwọn ti ọdọ wa jade, ṣugbọn nwọn
kò ti si ninu wa; nitori nwọn iba ti wà
ninu wa, nwọn iba bá wa duro: ṣugbọn
nwọn jade ki a le fi wọn hàn pe gbogbo
nwọn kì iṣe ti inu wa.
20 Ṣugbọn ẹnyin ni itorórosi lati ọdọ
Ẹni Mimọ́ nì wá, ẹnyin si mọ̀ ohun gbogbo.
21 Emi kò kọwe si nyin nitoripe ẹnyin
kò mọ̀ otitọ, ṣugbọn nitori ti ẹnyin mọ̀ ọ,
ati pe kò si eke ninu otitọ.
22 Tani iṣe eleke bikoṣe ẹniti o ba sẹ́ pe
Jesu kì iṣe Kristi? On ni Aṣodisi-Kristi,
ẹniti o ba sẹ́ Baba ati Ọmọ.
23 Ẹnikẹni ti o ba sẹ́ Ọmọ, on na ni kò
gbà Baba: ṣugbọn ẹniti o ba jẹwọ Ọmọ o
gbà Baba pẹlu.
24 Nitorina ki eyini ki o duro ninu
nyin, ti ẹnyin ti gbọ́ li àtetekọṣe. Bi eyi
ti ẹnyin ti gbọ́ li àtetekọṣe ba bá nyin
duro, ẹnyin o si duro pẹlu ninu Ọmọ ati
ninu Baba.
25 Eyi si ni ileri na ti o ti ṣe fun wa,
ani ìye ainipẹkun.
26 Nkan wọnyi ni mo kọwe si nyin ni-
pasẹ awọn ti ntàn nyin jẹ.
27 Ṣugbọn itorórosi ti ẹnyin ti gbà lọwọ
rẹ̀ o bá nyin duro, ẹnyin kò si ni pe ẹnikan
nkọ́ nyin: ṣugbọn bi itorórosi na ti nkọ́
nyin ninu ohun gbogbo, ti on si iṣe otitọ,
ti kì si iṣe eke, ati gẹgẹ bi o ti kọ́ nyin,
ẹnyin o si duro ninu rẹ̀.
28 Njẹ nisisiyi, ẹnyin ọmọde, ẹ duro
ninu rẹ̀; nipe, nigbati on o ba farahàn, ki
awa ki o le ni igbẹkẹle, ki a má si ṣe tiju
niwaju rẹ̀ nigba abọ̀ rẹ̀,
29 Bi ẹnyin ba mọ̀ pe olododo ni, ẹ mọ̀
pe a bí olukuluku ẹniti nṣe ododo ninu rẹ̀.

## ORI 3.

KIYESI i, irú ifẹ ti Baba fi fun wa, pe
ki a le mã pè wa li ọmọ Ọlọrun: ni-
torina aiye kò mọ̀ wa, nitoriti kò mọ̀ ọ.
2 Olufẹ, njẹ nisisiyi ọmọ Ọlọrun li awa
iṣe, kò si ti ihàn bi awa o ti jasi: ṣugbọn
awa mọ̀ pe, nigbati on o farahàn, awa o
dabi rẹ̀; nitori awa o ri i bi on ti ri.
3 Ati olukuluku ẹniti o ba ni ireti yi
ninu rẹ̀, a wẹ̀ ara rẹ̀ mọ́, gẹgẹ bi on si ti
mọ́.
4 Ẹnikẹni ti o dẹṣẹ o ru ofin pẹlu: nito-
ri ẹ̀ṣẹ ni riru ofin.
5 Ẹnyin si mọ̀ pe, on farahàn lati mu
ẹ̀ṣẹ wa kuro; ati lara rẹ̀ ẹ̀ṣẹ kò si.
6 Ẹnikẹni ti o ba ngbé inu rẹ̀ kò ṣẹ̀:
ẹnikẹni ti o ba ṣẹ̀ kò ri i, bẹ̃ni kò mọ̀ ọ.
7 Ẹnyin ọmọde ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni ki
o tàn nyin: ẹniti o ba nṣe ododo, o jasi
olododo, gẹgẹ bi on ti iṣe olododo.
8 Ẹnikẹni ti o ba dẹṣẹ ti Èṣu ni; nito-
riti Èṣu ti ṣẹ̀ lati igba àtetekọṣe. Nitori
idi eyi li Ọmọ Ọlọrun farahàn, ki o le pa
iṣẹ Èṣu run.
9 Ẹnikẹni ti a bí nipa ti Ọlọrun kò
dẹṣẹ; nitoriti irú rẹ̀ mbẹ ninu rẹ̀: on kò si
le ṣẹ̀, nitoriti a bí i nipa ti Ọlọrun.
10 Ninu eyi li a nfi awọn ọmọ Ọlọrun
hàn, ati awọn ọmọ Èṣu: ẹnikẹni ti kò ba
ṣe ododo kì iṣe ti Ọlọrun, ati ẹniti kò fẹràn
arakọnrin rẹ̀.
11 Nitori eyi ni ọ̀rọ ti ẹnyin gbọ́ li
àtetekọṣe, ki awa ki o le mã fẹràn ara wa.
12 Ki iṣe bi Kaini, ti iṣe ti ẹni buburu
nì, ti o si pa arakọnrin rẹ̀? Nitori kili o
ṣe pa a? Nitoriti iṣẹ on ṣe buburu, ti ti
arakọnrin rẹ̀ si ṣe rere.
13 Ki ẹnu ki o máṣe yà nyin, ẹnyin ará
mi, bi aiye ba korira nyin.
14 Awa mọ̀ pe awa ti kọja lati inu ikú
sinu ìye, nitori ti awa fẹràn awọn ará.
Ẹnikẹni ti kò ba fẹràn arákọnrin rẹ̀ o ngbé
inu ikú.
15 Ẹnikẹni ti o ba korira arakọnrin rẹ̀
on ni olupani: ẹnyin si mọ̀ pe ìye ainipẹ-
kun kò le ba olupani kan gbé.
16 Nipa eyi li awa mọ̀ ifẹ Ọlọrun, nito-
riti o fi ẹmí rẹ̀ lelẹ fun wa: o si yẹ ki awa
fi ẹmí wa lelẹ fun awọn ará.
17 Ṣugbọn ẹniti o ba ni ohun rere aiye
yi, ti o si ri arakọnrin rẹ̀ ti iṣe alaini, ti o
si sé iyọ́nu rẹ̀ mọ ọ, bawo ni ifẹ Ọlọrun ti
ngbé inu rẹ̀?
18 Ẹnyin ọmọde mi, ẹ máṣe jẹ ki a fi
kìki ẹnu ṣe ifẹ, tabi kìki ahọn; bikoṣe ni
iṣe ati ni otitọ.
19 Ati nipa eyi li awa mọ̀ pe awa mbẹ
ni ti inu otitọ, ati pe awa o si ṣe dajudaju
ọkàn wa niwaju rẹ̀.
20 Nitori bi ọkàn wa ba dá wa lẹbi,
Ọlọrun tobi jù ọkàn wa lọ, o si mọ̀ ohun
gbogbo.
21 Olufẹ bi ọkàn wa kò ba dá wa lẹbi,
njẹ awa ni igbẹkẹle sipa ti Ọlọrun.
22 Ati ohunkohun ti awa ba bère, awa

Digitized by Google

ri gbà lọdọ rẹ̀, nitori ti awa pa ofin rẹ̀ mọ́, ti awa si nṣe nkan wọnni ti o ṣe ohun ìwu niwaju rẹ̀.

23 Evi si li ofin rẹ̀, pe ki awa ki o le gbà orukọ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ gbọ́, ki a si fẹràn ara wa, gẹgẹ bi o ti fi ofin fun wa.

24 Ẹniti o ba si pa ofin rẹ̀ mọ́ o mba a gbé inu rẹ̀, ati on ninu rẹ̀. Ati nipa eyi li awa mọ̀ pe o mba wa gbé inu wa, nipa Ẹmí ti o fifun wa.

## ORI 4.

OLUFẸ, ẹ máṣe gbà gbogbo ẹmí gbọ́, ṣugbọn ẹ dán awọn ẹmí wò bi nwọn ba ṣe ti Ọlọrun: nitoriti awọn woli eke pupọ̀ ti jade lọ sinu aiye.

2 Nipa eyi ni ki ẹnyin ki o fi mọ̀ Ẹmí Ọlọrun: Gbogbo ẹmí ti o ba jẹwọ pe, Jesu Kristi wá nipa ti ara, ti Ọlọrun ni:

3 Gbogbo ẹmí ti kò si jẹwọ pe, Jesu Kristi wá nipa ti ara, kì iṣe ti Ọlọrun: eyi li ẹmí Aṣodisi-Kristi na, nipa eyi ti ẹnyin ti gbọ́ pe yio de; ani nisisiyi o si mbẹ ninu aiye na.

4 Ti Ọlọrun li ẹnyin, ọmọde, ẹnyin si ti ṣẹgun wọn: nitoripe atobijù li ẹniti mbẹ ninu nyin, jù ẹniti o mbẹ ninu aiye lọ.

5 Ti inu aiye ni nwọn: nitorina ni nwọn ṣe nsọ ti aiye, aiye si gbọ́ ti wọn.

6 Ti Ọlọrun li awa: ẹniti o ba mọ̀ Ọlọrun o gbọ́ ti wa; ẹniti kì iṣe ti Ọlọrun kò gbọ́ ti wa. Nipa eyi li awa mọ̀ ẹmí otitọ, ati ẹmí eke.

7 Olufẹ, ẹ jẹ ki a fẹràn ara wa: nitoripe ifẹ ni ti Ọlọrun; ati gbogbo ẹniti o ba fẹni a bí i nipa ti Ọlọrun, o si mọ̀ Ọlọrun.

8 Ẹniti ko ba ṣe ifẹ kò mọ Ọlọrun; nitoripe Ọlọrun ni ifẹ.

9 Ninu eyi li a gbé fi ifẹ Ọlọrun hàn si wa, nitoriti Ọlọrun rán Ọmọ bíbi rẹ̀ nikanṣoṣo si aiye yi, ki awa ki o le yè nipasẹ rẹ̀.

10 Nipa eyi ni ifẹ, kì iṣe pe ti awa fẹ Ọlọrun, bikoṣe pe o fẹ wa, o si rán Ọmọ rẹ̀ ṣe ètutu fun ẹ̀ṣẹ wa.

11 Olufẹ, bi Ọlọrun ba fẹ wa tobẽ̃, o yẹ ki a fẹràn ara wa pẹlu.

12 Ẹnikẹni kò ri Ọlọrun nigba kan ri. Bi awa ba fẹràn ara wa, Ọlọrun mba wa gbé, a si mu ifẹ rẹ̀ pé ninu wa.

13 Nipa eyi li awa mọ̀ pe awa mba a gbé inu rẹ̀, ati on ninu wa, nitoriti o ti fi Ẹmí rẹ̀ fun wa.

14 Awa si ti ri, a si jẹri, pe Baba rán Ọmọ lati ṣe Olugbala fun araiye.

15 Ẹnikẹni ti o ba jẹwọ pe Jesu Ọmọ Ọlọrun ni, Ọlọrun ngbé inu rẹ̀, ati on ninu Ọlọrun.

16 Awa si ti mọ̀, a si gbà ifẹ ti Ọlọrun ni si wa gbọ́. Ọlọrun ni ifẹ; ẹniti o ba si ngbé inu ifẹ o ngbé inu Ọlọrun, ati Ọlọrun ninu rẹ̀.

17 Nipa eyi li a mu ifẹ wa pé, ki awa ki o le ni igboiya li ọjọ idajọ: nitoripe bi on ti ri, bẽli awa si ri li aiye yi.

18 Ìbẹru kò si ninu ifẹ; ṣugbọn ifẹ ti o pé o lé ìbẹru jade: nitoriti ìbẹru ni oró. Ẹniti o bẹru kò pé ninu ifẹ.

19 Awa fẹ ẹ, nitoriti on tète fẹ wa.

20 Bi ẹnikan ba wipe, Emi fẹ Ọlọrun, ti o si korira arakọnrin rẹ̀, eleke ni: nitori ẹniti kò fẹ arakọnrin rẹ̀ ti o ri, yio ti ṣe fẹ Ọlọrun ti on kò ri?

21 Ofin yi li awa si ri gbà lati ọwọ́ rẹ̀ wá, Pe ẹniti o ba fẹ Ọlọrun, o fẹ arakọnrin rẹ̀ pẹlu.

## ORI 5.

ẸNIKẸNI ti o ba gbagbọ́ pe Jesu ni Kristi, a bí i nipa ti Ọlọrun: ati gbogbo ẹni ti o fẹ ẹniti o bíni, o fẹ ẹniti a bí nipasẹ rẹ̀ pẹlu.

2 Nipa eyi li awa mọ̀ pe awa fẹ awọn ọmọ Ọlọrun, nigbati awa fẹ Ọlọrun, ti a si pa ofin rẹ̀ mọ́.

3 Nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, ki awa ki o pa ofin rẹ̀ mọ́: ofin rẹ̀ kò si ni iroju.

4 Nitori ẹnikẹni ti a bí nipa ti Ọlọrun o ṣẹgun aiye: eyi si ni iṣẹgun ti o ṣẹgun aiye, ani igbagbọ́ wa.

5 Tani ẹniti o ṣẹgun aiye, bikoṣe ẹniti o gbogbọ́ pe Jesu ni Ọmọ Ọlọrun?

6 Eyi li ẹniti o wá nipa omi on ẹ̀jẹ, ani Jesu Kristi: kì iṣe ni kìki ipa omi, bikoṣe nipa omi on ẹ̀jẹ. Ẹmí li o si njẹri, nitoripe otitọ li Ẹmí na.

7 Nitoripe ẹni mẹta li o njẹri li ọrun, Baba, Ọ̀rọ, ati Ẹmí Mimọ́: awọn mẹtẹta yi si jasi ọkan.

8 Awọn mẹta li o si njẹri li aiye, Ẹmí, ati omi, ati ẹ̀jẹ: awọn mẹtẹta yi si jasi ọkan.

9 Bi awa ba gbà ẹrí enia, ẹrí Ọlọrun pọ̀ju: nitori eyi li ẹrí Ọlọrun ti o ti jẹ́ nipa ti Ọmọ rẹ̀.

10 Ẹniti o ba gbà Ọmọ Ọlọrun gbọ́ o ni ẹrí ninu ara rẹ̀: ẹniti kò ba gbà Ọlọrun gbọ́, o ti mu u li eke; nitoriti kò gbà ẹrí na gbọ́ ti Ọlọrun jẹ́ nipa li Ọmọ rẹ̀.

11 Eyi si li ẹrí, pe Ọlọrun ti fun wa ni ìye ainipẹkun, ìye yi si mbẹ ninu Ọmọ rẹ̀.

Digitized by Google

12 Ẹniti o ba ni Ọmọ, o ni iye; ẹniti kò
ba si ni Ọmọ Ọlọrun, kò ni iye.
13 Nkan wọnyi ni mo kọwe si ẹnyin ti
o gbà orukọ Ọmọ Ọlọrun gbọ́; ki ẹnyin ki
o le mọ̀ pe ẹnyin ni iye ainipẹkun, ati ki
ẹnyin ki o le gbà orukọ Ọmọ Ọlọrun gbọ́.
14 Eyiyi si ni igbẹkẹle ti awa ni nipa
ọdọ rẹ̀, pe bi awa ba bère ohunkohun gẹgẹ
bi ifẹ tirẹ̀, o gbọ́ ti wa:
15 Bi awa ba si mọ̀ pe o gbọ́ ti wa,
ohunkohun ti awa ba bère, awa mọ̀ pe awa
ni ibere ti awa nwá lọdọ rẹ̀.
16 Bi ẹnikan ba ri arakọnrin rẹ̀ ti nṣẹ̀
ẹ̀ṣẹ ti kì iṣe si ikú, ki on ki o bère, on o si
fi iye fun awọn ti kò ṣẹ̀ si ikú. Ẹ̀ṣẹ kan
mbẹ si ikú: emi kò wipe ki on ki o gbadura
fun u.
17 Aiṣododo gbogbo li ẹ̀ṣẹ: ẹ̀ṣẹ kan si
mbẹ li aiṣe si ikú.
18 Awa mọ̀ pe ẹnikẹni ti a bí ni ti Ọlọ-
run kì iṣẹ̀; ṣugbọn ẹniti a ba bí ni ti Ọlọ-
run o pa ara rẹ̀ mọ́, ẹni buburu nì kò si fi
ọwọ́ kàn a.
19 Awa si mọ̀ pe awa mbẹ ninu ti Ọlọ-
run, ati gbogbo aiye li o dubulẹ ninu ẹni
buburu nì.
20 Awa si mọ̀ pe Ọmọ Ọlọrun de, o si ti
fi oyé fun wa, ki awa ki o le mọ̀ ẹniti iṣe
otitọ, awa si mbẹ ninu ẹniti iṣe otitọ, ani
ninu Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀. Eyiyi li Ọlọrun
otitọ, ati iye ainipẹkun.
21 Ẹnyin ọmọde, ẹ pa ara nyin mọ́ kuro
ninu oriṣa. Amin.

---

EPISTELI EKEJI TI

# JOHANNU.

ALÀGBA si ayanfẹ obirin ọlọlá ati si awọn
ọmọ rẹ̀, ẹniti mo fẹ nipa otitọ; kì si
iṣe emi nikanṣoṣo, ṣugbọn ati gbogbo awọn
ti o mọ̀ otitọ pẹlu;
2 Nitori ti otitọ, ti mba wa gbé, ti yio
si ma ba wa gbé titi lai.
3 Ore-ọfẹ pẹlu nyin, ãnu, ati alafia, lati
ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati lati ọdọ Oluwa
Jesu Kristi, Ọmọ Baba, ninu otitọ ati ninu
ifẹ.
4 Mo yọ̀ gidigidi pe mo ri ninu awọn
ọmọ rẹ nrìn ninu otitọ, bi awa ti gbà ofin
lọwọ Baba.
5 Njẹ nisisiyi emi bẹ̀ ọ, obirin ọlọlá, kì
iṣe bi ẹnipe emi kọwe ofin titun kan si ọ,
bikoṣe eyi ti awa ti ni li àtetekọṣe, pe ki
awa ki o fẹràn ara wa.
6 Eyi si ni ifẹ, ki awa ki o ma rìn nipa
ofin rẹ̀. Eyi li ofin na, pe, bi ẹnyin ti gbọ́
li àtetekọṣe, ki ẹ si mã rìn ninu rẹ̀.
7 Nitori ẹlẹtàn pupọ̀ wọ̀ inu aiye, ti kò
jẹwọ pe: Jesu Kristi wá nipa ti ara. Ẹlẹ-
tàn li eyini ati Aṣodisi-Kristi.
8 Ẹ bojuto ara nyin, ki awa ki o máṣe
sọ ohun wọnni ti awa ti ṣe nù, bikoṣe pe ki
a ri ère kíkun gbà.
9 Ẹnikẹni ti o rufin, ti kò si duro ninu
ẹkọ́ Kristi, kò gbà Ọlọrun. Ẹniti o ba duro
ninu ẹkọ́ Kristi, on li o gbà ati Baba ati
Ọmọ.
10 Bi ẹnikẹni ba tọ̀ nyin wá, ti kò si mu
ẹkọ́ yi wá, ẹ máṣe gbà a sinu ile nyin, bẹ̃ni
ki ẹ má si ṣe súre ọ̀na rere fun u:
11 Nitori ẹniti o ba súre ọ̀na rere fun u,
o ni ọwọ́ ninu iṣẹ buburu rẹ̀.
12 Ni bi mo ti ni ohun pupọ̀ lati kọwe
si nyin, emi kò fẹ fi iwe ati tadawa kọwe si
nyin: ṣugbọn emi gbẹkẹle lati tọ̀ nyin wá,
ati lati ba nyin sọrọ li ojukoju, ki ayọ̀ wa
ki o le kún.
13 Awọn ọmọ arabirin rẹ ayanfẹ ki ọ.
Amin.

Digitized by Google

EPISTELI EKETA TI

# JOHANNU.

ALÀGBA si Gaiu olufẹ gidigidi ẹniti mo
fẹ ninu otitọ.
2 Olufẹ, mo fẹ jù ohun gbogbo lọ ki iwọ
ki o le ma wà li alafia, ki o si wà ni ilera,
gẹgẹ bi ọkàn rẹ ti mbẹ li alafia.
3 Nitori mo yọ̀ gidigidi, nigbati awọn
arakọnrin de, ti nwọn si njẹri otitọ ti o
mbẹ ninu rẹ, gẹgẹ bi iwọ ti nrìn ninu
otitọ,
4 Emi kò ni ayọ̀ ti o tobijù bẹ̃ lọ, bi ki
emi ki o mã gbọ́ pe, awọn ọmọ mi nrìn
ninu otitọ.
5 Olufẹ, iwọ nṣe nitõtọ li ohunkohun ti
iwọ nṣe fun awọn ará, ati fun awọn alejò ;
6 Ti o njẹri ifẹ rẹ niwaju ijọ : ẹniti bi
iwọ ba nmu wọn lọ siwaju li ọ̀na àjo wọn
nipa ìwabi-Ọlọrun, iwọ o ṣe rere :
7 Nitoripe nitori orukọ rẹ̀ ni nwọn ṣe
jade lọ, li aigbà nkan lọwọ awọn Keferi.
8 Njẹ o yẹ ki awa ki o gbà irú awọn
wọnni, ki awa ki o le jẹ alabaràn-lọwọ si
otitọ.
9 Emi kọwe si ijọ : ṣugbọn Diotrefe,
ẹniti o fẹ lati ṣe olori gbogbo larin wọn, kò
gbà wa.
10 Nitorina bi mo ba de, emi o ranti iṣe
rẹ̀ ti o ṣe, o nfi ọ̀rọ arankàn ṣeféfe si wa :
eyini kò si tẹ́ ẹ lọrùn, bẹ̃ni on tikararẹ̀ kò
gbà awọn arakọnrin, o si ndá awọn ti iba
gbà wọn lẹkun, o nlé wọn jade kuro ninu
ijọ.
11 Olufẹ, máṣe tọ̀ ohun ti iṣe buburu
lẹhin, bikoṣe ohun ti iṣe rere. Ẹniti o ba
nṣe rere ti Ọlọrun ni : ṣugbọn ẹniti o ba
nṣe buburu kò mọ̀ Ọlọrun.
12 Demetriu li orukọ rere lọdọ gbogbo
enia, ati ni ti otitọ pẹlu : nitõtọ, awa pẹlu
si gbà ẹrí rẹ̀ jẹ ; ẹnyin si mọ̀ pe ẹrí wa otitọ
ni.
13 Emi ni ohun pupọ̀ lati kọwe, ṣugbọn
emi kì yio fi tadawa on kalamu kọwe
si ọ :
14 Ṣugbọn emi gbẹkẹle pe emi o ri ọ
nisisiyi, ati pe awa o si sọ̀rọ li ojukoju.
Alafia fun ọ. Awọn ọrẹ́ kí ọ. Kí awọn
ọrẹ́ li orukọ-orukọ.

---

EPISTELI TI

# JUDA

## FUN ENIA GBOGBO.

JUDA, iranṣẹ Jesu Kristi, ati arakọnrin
Jakọbu, si awọn ti a sọdi mimọ́ lati
ọwọ́ Ọlọrun Baba wá, ti a si pamọ́ ninu
Jesu Kristi, ti a si pè :
2 Ãnu fun nyin, ati alafia, ati ifẹ, ki o
ma bi si i.
3 Olufẹ, nigbati mo fi aisimi gbogbo
kọwe si nyin nitori igbala ti o wọpọ̀, o tọ́
fun mi lati kọwe si nyin, ki emi si gbà
nyin niyanju, ki ẹnyin ki o le ma fi itara
tẹnumọ igbagbọ́, ti ati fifun awọn enia
mimọ́ lẹkan.
4 Nitori awọn enia kan mbẹ ti nwọn nyọ́
wọnú li aifarahàn, nigba atijọ ẹni ti a ti
yàn si ẹbi yi, enia alaiwabi-Ọlọrun, ti nyi
ore-ọfẹ Ọlọrun wa pada si iwọbia, ti nwọn
si nsẹ́ Oluwa Ọlọrun kanṣoṣo na, ati Jesu
Kristi Oluwa wa.

Digitized by Google

5 Nitorina emi o rán nyin leti, bi ẹnyin tilẹ ti mọ̀ ọ lẽkan, pe bi Oluwa, nigbati o gbà awọn enia là tan lati ilẹ Egipti wá, lẹhinna o run awọn ti kò gbagbọ́.

6 Ati awọn angeli ti kò duro ni ipò wọn iṣaju, ṣugbọn ti nwọn fi ipò oyè wọn silẹ, awọn li o pamọ́ dè ẹ̀wọn ainipẹkun nisalẹ òkunkun titi di ọjọ nla nì.

7 Ani bi Sodomu ati Gomorra, ati ilu agbegbe wọn wọnni bẽ gẹgẹ, ti nwọn fi ara wọn fun àgbere iṣe, ti nwọn nlò ara òdi, awọn li o si fi lelẹ ṣe apẹrẹ, nwọn njìya ẹsan ti iná ainipẹkun.

8 Bẽ gẹgẹ pẹlu li awọn alalá ẹgbin wọnyi, ti nsọ ara di ẽri, ti ngàn ijoye, ti nwọn si nsọ̀rọ buburu si awọn ọlọlá.

9 Ṣugbọn Mikaeli, olori awọn angeli, nigbati mba Èṣu jà, ti o nṣe ọpalaye nitori ara okú Mose, kò si gbọdọ mu ọ̀rọ ẹ̀gan tọ̀ ọ wá, ṣugbọn o wipe, Oluwa ni yio ba ọ wi.

10 Ṣugbọn awọn wọnyi nsọ̀rọ ibi si ohun ti nwọn kò mọ̀: ṣugbọn ohun ti nwọn mọ̀ nipa ẹda, bi ẹranko, ninu nkan wọnni ni nwọn mbà ara wọn jẹ.

11 Egbé ni fun wọn! nitoriti nwọn ti rìn li ọ̀na Kaini, nwọn si fi iwọra sure tọ̀ ìṣina Balaamu lẹhin nitori ère, nwọn si ṣegbé ninu ariwisi Kora.

12 Wọnyi li abawọn ninu àse ifẹ nyin, nigbati nwọn mbà nyin jẹ, nwọn nfi aibẹ̀ru bọ́ ara wọn: ikũku ni nwọn laini omi, ti a nti ọwọ́ afẹfẹ gbá kiri; igi ti eso rẹ̀ rẹ̀ silẹ, laini eso, o kú lẽmeji, ti a fàtu ni gbòngbo;

13 Omi okun ti nru, ti nhó ifofó itiju ara wọn jade; alarinkiri irawọ, ti a pa dudu òkunkun mọ́ dè lailai.

14 Ati Enoku pẹlu, ẹni ikeje lati Adamu wá, o sọ̀rọ wọnyi tẹlẹ pe, Kiyesi i, Oluwa mbọ̀wa pẹlu ẹgbãrun awọn enia rẹ̀ mimọ́,

15 Lati ṣe idajọ si ori awọn enia gbogbo, ati lati mu oyé yé gbogbo awọn ti iṣe alaiwabi-Ọlọrun ninu wọn, niti gbogbo iṣe aiwabi-Ọlọrun, ti nwọn ti nfi aiwabi-Ọlọrun ṣe, ati ninu gbogbo ọ̀rọ lile wọn, ti awọn ẹlẹṣẹ alaiwabi-Ọlọrun ti sọ si i.

16 Awọn wọnyi li alakùn sinu, alaroye, ti nrìn nipa ifẹkufẹ ara wọn; ẹnu wọn a si mã sọ ọ̀rọ asan nla, nwọn mbù iyìn fun ara enia nitori anfani.

17 Ṣugbọn ẹnyin, olufẹ, ẹ ranti ọ̀rọ ti a ti sọ fun nyin ṣaju lati ọwọ́ awọn aposteli Jesu Kristi Oluwa wa;

18 Bi nwọn ti wi fun nyin pe, awọn ẹlẹgàn yio wà nigba ikẹhin, ti nwọn o mã rìn nipa ifẹkufẹ ara wọn li aiwabi-Ọlọrun.

19 Awọn wọnyi ni nyà ara wọn sọtọ̀, agbọtara, li aini Ẹmí.

20 Ṣugbọn ẹnyin, olufẹ, ti ẹ nró ara nyin soke lori igbagbọ́ nyin ti o mọ́ julọ, ẹ mã gbadura nipa Ẹmí Mimọ́,

21 Ẹ mã pa ara nyin mọ́ ninu ifẹ Ọlọrun, ẹ mã wò ãnu Jesu Kristi Oluwa wa, titi aiye ainipẹkun.

22 Ati fun awọn ẹlomiran ẹ mã ṣãnu, ẹ mã ṣe iyatọ:

23 Ati awọn miran ẹ mã fi ìbẹru gbalà, ẹ mã fà wọn yọ kuro ninu iná; ẹ tilẹ mã korira aṣọ ti o di abawọn nipa ti ara.

24 Njẹ fun ẹniti o le pa nyin mọ́ kuro ninu iṣubu, ati lati mu nyin wá siwaju ogo rẹ̀ pẹlu ayọ̀ nla li aini àbuku,

25 Fun Ọlọrun ọlọ́gbọn nikanṣoṣo, Olugbala wa, ogo ati ọlánla, ijọba ati agbara, mbẹ fun ati nisisiyi ati lailai. Amin.

IFIHÀN (IṢIPAYA) TI

# JOHANNU.

## ORI 1.

IFIHÀN ti Jesu Kristi, ti Ọlọrun fifun u, lati fihàn fun awọn iranṣẹ rẹ̀ ohun ti kò le ṣe ki o má ṣẹ ni lọ̃lọ̃; o si ranṣẹ o si fi i hàn lati ọwọ́ angeli rẹ̀ wá fun Johannu, iranṣẹ rẹ̀:

2 Ẹniti o jẹri ọ̀rọ Ọlọrun, ati ẹrí Jesu Kristi, ati ti ohun gbogbo ti o ri.

3 Olubukún li ẹniti o nkà, ati awọn ti o ngbọ́ ọ̀rọ isọtẹlẹ yi, ti o si npa nkan wọnni ti a kọ sinu rẹ̀ mọ́: nitori igba kù si dẹ̀dẹ.

4 JOHANNU si Ijọ meje ti mbẹ ni Asia: Ore-ọfẹ si nyin, ati alafia, lati ọdọ rẹ̀ wá

Digitized by Google

ẹniti o mbọ, ti o ti wà, ti o si mbọ̀wa ; ati
lati ọdọ awọn Ẹmí meje nì wá ti mbẹ
niwaju itẹ́ rẹ̀ ;
5 Ati lati ọdọ Jesu Kristi wá, ẹniti iṣe
ẹlẹri olõtọ, ẹni akọbi ninu awọn okú, ati
alaṣẹ awọn ọba aiye. Si ẹniti o fẹ wa, ti o
si wẹ̀ wa ninu ẹ̀jẹ ara rẹ̀ kuro ninu ẹ̀ṣẹ
wa,
6 Ti o si ti fi wa jẹ ọba, ati alufa si Ọlọ-
run ati Baba rẹ̀ ; on ni ki a fi ogo ati ijọba
fun lai ati lailai. Amin.
7 Kiyesi i, o mbọ̀ ninu awọsanma ; gbo-
gbo oju ni yio si ri i, ati awọn ti o gún u li
ọ̀kọ pẹlu ; ati gbogbo ibatan aiye ni yio si
ma pohùnrere ẹkún nitori rẹ̀. Bẹ̃ni, Amin.
8 Emi ni Alfa ati Omega, ipilẹṣẹ ati
opin, li Oluwa wi, ẹniti o mbọ, ti o ti wà,
ti o si mbọ̀wa, Olodumare.
9 Emi Johannu, ẹni pẹlu ti iṣe arakọn-
rin ati ẹgbẹ nyin ninu ipọnju, ati ninu
ijọba ati sũru Jesu Kristi, mo wà ninu ere-
kuṣu, ti a npè ni Patmo, nitori ọ̀rọ Ọlọrun,
ati nitori ẹri Jesu Kristi.
10 Mo wà ninu Ẹmí li ọjọ Oluwa, mo si
gbọ́ ohùn nla lẹhin mi, bi iró ipè.
11 O nwipe, Emi ni Alfa ati Omega, ẹni-
iṣaju ati ẹni-ikẹhin : Ohun ti iwọ si ri, kọ
ọ sinu iwe, ki o si rán a si Ijọ mejeje ti
mbẹ ni Asia ; si Efesu, ati si Smirna, ati si
Pergamu, ati si Tiatira, ati si Sardi, ati si
Filadelfia, ati si Laodikea.
12 Mo si yipada lati wò ohùn ti mba mi
sọ̀rọ. Nigbati mo yipada, mo ri ọpá wura
fitila meje ;
13 Ati larin ọpá fitila meje yi ẹnikan ti
o dabi Ọmọ enia, a wọ̀ ọ li aṣọ ti o kànlẹ
de ẹsẹ rẹ̀, a si fi àmure wura dì i li ẹgbẹ.
14 Ori rẹ̀ ati irun rẹ̀ dabi ẹgbọn owu, o
funfun bi ojo-didì ; oju rẹ̀ si dabi ọwọ́
iná ;
15 Ẹsẹ rẹ̀ si dabi idẹ daradara, bi ẹnipe
a sun u ninu ileru ; ohùn rẹ̀ si dabi iró omi
pupọ̀.
16 O si ni irawọ meje li ọwọ́ ọtún rẹ̀ :
ati lati ẹnu rẹ̀ wá ni idà oloju meji mimu
ti jade : ìwo oju rẹ̀ si dabi õrùn ti o nfi
agbara rẹ̀ ràn.
17 Nigbati mo ri i, mo wolẹ li ẹsẹ rẹ̀ bi
ẹniti o kú. O si fi ọwọ́ ọtún rẹ̀ le mi, o nwi
fun mi pe, Máṣe bẹ̀ru ; Emi ni ẹni-iṣaju ati
ẹni-ikẹhin :
18 Emi li ẹniti o mbẹ lãye, ti o si ti kú;
si kiyesi i, emi si mbẹ lãye si i titi lai,
Amin ; mo si ní ọmọ-ṣika iku ati ti Ipo-
oku.
19 Kọwe ohun gbogbo ti iwọ ti ri, ati ti
ohun ti mbẹ, ati ti ohun ti yio hù lẹhin
eyi ;
20 Ohun ijinlẹ ti irawọ meje nì ti iwọ ri
li ọwọ́ ọtún mi, ati ọpá wura fitila meje nì.
Irawọ meje nì ni awọn angeli Ijọ meje nì :
ati ọpá fitila meje nì ti iwọ ri ni awọn ijọ
meje.

## ORI 2.

SI angeli ijọ ti Efesu kọwe ; Nkan wọnyi
li ẹniti o mu irawọ meje nì li ọwọ́ ọtún
rẹ̀, ẹniti nrìn li arin ọpá wura fitila meje
nì wipe,
2 Emi mọ̀ iṣẹ rẹ, ati lãlã rẹ, ati sũru rẹ,
ati bi iwọ kò si ti le mu sũru fun awọn ẹni
buburu : ati bi iwọ si ti dán awọn ti nwipe
aposteli li awọn, ti kì iṣe bẹ̃, ti iwọ si mu
wọn li eke :
3 Ti iwọ si gbà ìya si ara, ti iwọ si mu
sũru, ati nitori orukọ mi ti o si ṣe lãlã, ti
ãrẹ̀ kò si mu ọ.
4 Ṣugbọn mo ni nkan iwi si ọ, nitoriti
iwọ ti fi ifẹ rẹ iṣaju silẹ.
5 Nitorina ranti ibiti iwọ gbé ti ṣubu lọ,
ki o si ronupiwada, ki o si ṣe iṣẹ iṣaju ; bi
kò si ṣe bẹ̃, emi o si tọ̀ ọ wá nisisiyi, emi o
si ṣí ọpá fitila rẹ kuro ni ipò rẹ̀, bikoṣe bi
iwọ ba ronupiwada.
6 Ṣugbọn eyi ni iwọ ní, ti iwọ korira iṣe
awọn Nikolaitani ti emi korira pẹlu.
7 Ẹniti o ba li etí ki o gbọ́ ohun ti Ẹmí
nsọ fun ijọ ; Ẹniti o ba ṣẹgun ni emi o fi
eso igi ìye nì fun jẹ, ti mbẹ larin Paradise
Ọlọrun.
8 Ati si angeli ijọ ti Smirna kọwe ;
Nkan wọnyi li ẹniti iṣe ẹni-iṣaju ati ẹni-
ikẹhin wi, ẹniti o ti kú, ti o si yè ;
9 Emi mọ̀ iṣẹ rẹ, ati ipọnju, ati aini rẹ,
(ṣugbọn iwọ li ọrọ̀) emi si mọ̀ ọ̀rọ ọ̀di si
Ọlọrun ti awọn ti nwipe Ju li awọn, ti kì
iṣe bẹ̃, ṣugbọn ti nwọn jẹ́ sinagogu ti Sa-
tani.
10 Máṣe bẹ̀ru ohunkohun ti iwọ o jẹ ni
ìya : kiyesi i, Èṣu yio gbé ninu nyin jù
sinu tubu, ki a le dán nyin wò ; ẹnyin o si
ni ipọnju ni ijọ mẹwa : iwọ sa ṣe olõtọ di
oju ikú, emi o si fi ade ìye fun ọ.
11 Ẹniti o ba li etí, ki o gbọ́ ohun ti Ẹmí
nsọ fun ijọ ; Ẹniti o ba ṣẹgun kì yio fi ara
pa ninu ikú keji.
12 Ati si angeli ijọ ti Pergamu kọwe ;
Nkan wọnyi li ẹniti o ni idà mimu oloju
meji nì wi pe,
13 Emi mọ̀ iṣẹ rẹ, ati ibiti iwọ ngbé, ani
nibiti ibujoko Satani wà : ati pe iwọ dì
orukọ mi mu ṣinṣin, ti iwọ kò si sẹ́ igbagbọ́

Digitized by Google

mi, ani li ọjọ wọnni ninu eyi ti Antipa iṣe
olõtọ ajẹri-kú mi, ẹniti nwọn pa ninu nyin,
nibiti Satani ngbé.
14 Ṣugbọn mo ni nkan diẹ iwi si ọ,
nitoriti iwọ ní awọn ti o dì ẹkọ́ ti Balaamu
mu nibẹ̀, ẹniti o kọ́ Balaku lati mu ohun
ikọsẹ̀ wá siwaju awọn ọmọ Israeli, lati mã
jẹ ohun ti a pa rubọ si oriṣa, ati lati mã ṣe
àgbere.
15 Bẽni iwọ si ní awọn ti o gbà ẹkọ́ awọn
Nikolaitani pẹlu, ohun ti mo korira.
16 Ronupiwada; bikoṣe bẽ emi o tọ̀ ọ
wá nisisiyi, emi o si fi idà ẹnu mi ba wọn jà.
17 Ẹniti o ba li etí, ki o gbọ́ ohun ti
Ẹmí nsọ fun ijọ; Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o
fi manna ti o pamọ́ fun jẹ, emi o si fun u li
okuta funfun kan, ati sara okuta na orukọ
titun ti a o kọ si i, ti ẹnikẹni kò mọ̀ bikoṣe
ẹniti o gbà a.
18 Ati si angeli ijọ ti Tiatira kọwe;
Nkan wọnyi li Ọmọ Ọlọrun wi, ẹniti o ni
oju rẹ̀ bi ọwọ́ iná, ti ẹsẹ rẹ̀ si dabi idẹ dara-
dara;
19 Emi mọ̀ iṣẹ rẹ, ati ịfẹ rẹ, ati ìsin, ati
igbagbọ́, ati sũru rẹ, ati iṣẹ-isin rẹ; ati pe
ti ikẹhin jù ti iṣaju lọ.
20 Ṣugbọn mo ni nkan diẹ iwi si ọ,
nitoriti iwọ jẹ ki obirin nì Jesebeli, ti o
npè ara rẹ̀ ni woli, lati mã kọ́ ẹkọ́, ati lati
mã tàn awọn ọmọ-ọdọ mi jẹ lati mã ṣe
àgbere, ati lati mã jẹ ohun ti a pa rubọ si
oriṣa.
21 Emi si fi sã fun u lati ronupiwada
àgbere rẹ̀; kò si ronupiwada.
22 Kiyesi i, emi o si wọ́ ọ si ori ẹní, ti on
ti awọn ti mba a ṣe panṣaga pẹlu rẹ̀, sinu
ipọnju nla, bikoṣe pe nwọn ba ronupiwada
iṣẹ wọn.
23 Emi o si fi ikú pa awọn ọmọ rẹ̀; gbo-
gbo ijọ ni yio si mọ̀ pe, emi li ẹniti nwadi
inu ati àiya: emi o si fifun olukuluku nyin
gẹgẹ bi iṣẹ nyin.
24 Ṣugbọn fun ẹnyin li emi wi, ati fun
awọn iyokù ni Tiatira pe, iye awọn ẹniti
kò gbà ẹkọ́ yi, ati ti kò ti mọ̀ ijinlẹ Satani,
(bi nwọn ti nwi); emi kì yio si dì ẹrù
miran kan rù nyin.
25 Ṣugbọn eyi ti ẹnyin ti gbà na, ẹ dì i
mu ṣinṣin titi emi o fi de.
26 Ẹniti o ba si ṣẹgun, ti o si pa iṣẹ mi
mọ́ de opin, on li emi o fi agbara fun lori
awọn orilẹ-ède:
27 On o si ma fi ọpá irin mu wọn sìn;
bi ohun-èlo amọ̀koko li a o fọ́ wọn tútu:
gẹgẹ bi mo ti gbà aṣẹ lọdọ Baba mi.
28 Emi o si fi irawọ owurọ̀ fun u.
29 Ẹniti o ba li etí, ki o gbọ́ ohun ti
Ẹmí nsọ fun ijọ.

## ORI 3.

ATI si angeli ijọ ti Sardi kọwe: Nkan
wọnyi li ẹniti o ni Ẹmí meje Ọlọrun,
ati irawọ meje nì wi pe; Emi mọ̀ iṣẹ rẹ,
ati pe iwọ ni orukọ pe iwọ mbẹ lãye, ṣu-
gbọn iwọ kú.
2 Mã ṣọra ki o si mu ohun ti o kù larale,
ti o ṣetan lati kú: nitoriti emi kò ri iṣẹ rẹ
ni pipé niwaju Ọlọrun.
3 Nitorina ranti bi iwọ ti gbà ti iwọ si
gbọ́, ki o si dì i mu ṣinṣin, ki o si ronupi-
wada. Njẹ bi iwọ kò ba mã ṣọra, emi o de
si ọ bi olè, iwọ kì yio si mọ̀ wakati ti emi
o de si ọ.
4 Iwọ ni orukọ diẹ ni Sardi pẹlu, ti kò
bà aṣọ wọn jẹ; nwọn o si mã ba mi rìn ni
funfun: nitori nwọn yẹ.
5 Ẹniti o ba ṣẹgun, on na li a o fi aṣọ
funfun wọ̀; emi kì yio si pa orukọ rẹ̀ rẹ́
kuro ninu iwe ìye, ṣugbọn emi o jẹwọ orukọ
rẹ̀ niwaju Baba mi, ati niwaju awọn angeli
rẹ̀.
6 Ẹniti o ba li etí, ki o gbọ́ ohun ti Ẹmí
nsọ fun ijọ.
7 Ati si angeli ijọ ti Filadelfia kọwe;
Nkan wọnyi li ẹni mimọ́ nì wi, ẹniti iṣe
olõtọ, ẹniti o ni ọmọ-ṣika Dafidi, ẹniti o ṣí,
ti ẹnikẹni kò si le sé; ti o si sé, ti ẹnikẹni
kò si le ṣí;
8 Emi mọ̀ iṣẹ rẹ: kiyesi i, mo gbé ilẹkun
ti o ṣí kalẹ niwaju rẹ, kò si si ẹniti o le sé
e: nitoriti iwọ li agbara diẹ, iwọ si pa ọ̀rọ
mi mọ́, iwọ kò si sẹ́ orukọ mi.
9 Kiyesi i, emi o mu awọn ti inu sina-
gogu Satani, ti nwipe Ju li awọn, ti nwọn
kì si iṣe bẽ, ṣugbọn ti nwọn nṣeke; kiyesi
i, emi o mu ki nwọn wá wolẹ niwaju ẹsẹ
rẹ, ati lati mọ̀ pe emi ti fẹ ọ.
10 Nitori iwọ ti pa ọ̀rọ sũru mi mọ́, emi
o si pa ọ mọ́ pẹlu ni wakati idanwò, ti
mbọ̀wa sori gbogbo aiye, lati dán awọn ti
o wà lori ilẹ aiye wò.
11 Kiyesi i, emi de nisisiyi: eyi ti iwọ
ni nì, dì i mu ṣinṣin, ki ẹnikẹni ki o máṣe
gbà ade rẹ.
12 Ẹniti o ba ṣẹgun on li emi o fi ṣe ọ̀pó
ni tempili Ọlọrun mi, on kì yio si jade mọ́:
emi o si kọ orukọ Ọlọrun mi si i lara, ati
orukọ ilu Ọlọrun mi, ti iṣe Jerusalemu
titun, ti o nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun
mi wá: emi o si kọ orukọ mi titun si i lara.
13 Ẹniti o ba li etí, ki o gbọ́ ohun ti
Ẹmí nsọ fun ijọ.

Digitized by Google

14 Ati si angeli ijọ ti Laodikea kọwe; Nkan wọnyi li ẹniti ijẹ Amin wi, olõtọ olododo ẹlẹri, olupilẹṣẹ dida aiye Ọlọrun;

15 Emi mọ̀ iṣẹ rẹ, pe iwọ kò gbóna bẽni iwọ kò tutù: mo fẹ pe iwọ iba kuku tutù tabi iwọ iba kuku gbóna.

16 Njẹ bẽ nitori ti iwọ ṣe ilọwọwọ, ti iwọ kò si tutù ti iwọ kò gbóna, emi o pọ̀ ọ jade kuro li ẹnu mi.

17 Nitoriti iwọ wipe, Emi li ọrọ̀, emi si npọ̀si i li ọjà tità, pe emi kò si ṣe alaini nkan; ti iwọ kò si mọ̀ pe, òṣi ni iwọ, ati are, ati talakà, ati afọju, ati ìhoho:

18 Emi fun ọ ni ìmọ pe, ki iwọ ki o rà wura lọwọ mi ti a ti danwò ninu iná, ki iwọ ki o le li·ọrọ̀; ati aṣọ funfun, ki a le wọ̀ ọ li aṣọ, ati ki itiju ìhoho rẹ ki o máṣe hàn; ki o si fi ìkunju kùn oju rẹ, ki iwọ ki o le riran.

19 Iye awọn ti.mo fẹ, li emi mba wi, ti mo si nà: nitorina iwọ ṣe itara, ki o si ronupiwada.

20 Kiyesi i, emi duro tì ilẹkun, emi si nkànkun: bi ẹnikẹni ba gbọ́ ohùn mi, ti o si ṣí ilẹkun, emi o si wọle tọ̀ ọ wá, emi o si ma ba a jẹun, ati on pẹlu mi.

21 Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fifun lati joko pẹlu mi lori itẹ́ mi, gẹgẹ bi emi si ti ṣẹgun, ti emi si joko pẹlu Baba mi lori itẹ́ rẹ̀.

22 Ẹniti o ba li etí, ki o gbọ́ ohun ti Ẹmí nsọ fun ijọ.

## ORI 4.

LẸHIN eyi li emi wò, si kiyesi i, ilẹkun kan ṣí silẹ li ọrun: ohùn ti mo si tẹtekọ gbọ́ dabi ti ipè ti mba mi sọ̀rọ; ti o wipe, Goke wa ìhin, emi o si fi ohun ti yio hù lẹhin ọla hàn ọ.

2 Lojukanna mo si wà ninu Ẹmí: si kiyesi i, a tẹ́ itẹ́ kan li ọrun, ẹnikan si joko lori itẹ́ na.

3 Ẹniti o si joko jẹ ẹniti a ba ma wò bi okuta jasperi, ati sardi: oṣumare si ta yi itẹ́ na ká kiri, ni wiwò rẹ̀ bi okuta smaragdu.

4 Ati rọgba yi itẹ́ na ká ni ibujoko mẹrinlelogun: ati lori ibujoko na mo ri awọn alàgba mẹrinlelogun joko, ti a wọ̀ li aṣọ àla; nwọn si ni ade wura li ori wọn.

5 Ati lati ibi itẹ́ na ni mànamána ati ãrá ati ohùn ti jade wá: fitila iná meje si ntàn nibẹ̀ niwaju itẹ́ na, ti iṣe Ẹmí meje ti Ọlọrun.

6 Ati niwaju itẹ́ na, okun digí kan wà o dabi kristali: ati li arin itẹ́ na, ati rọ̀gba yi itẹ́ na ká, li ẹda alãye mẹrin ti o kún fun oju ati niwaju ati lẹhin.

7 Ẹda alãye ikini si dabi kiniun, ẹda alãye keji si dabi ọmọ malu, ẹda alãye kẹta si ni oju bi ti enia, ẹda alãye kẹrin si dabi idì ti nfò.

8 Olukuluku awọn ẹda alãye mẹrẹrin si ni apa-iyẹ́ mẹfa-mẹfa yi i ká; nwọn si kun fun oju ninu: nwọn kò si simi li ọsán ati li oru, wipe, Mimọ́, mimọ́, mimọ́, Oluwa Ọlọrun Olodumare, ti o ti wà, ti o si mbẹ, ti o si mbọ̀wa.

9 Nigbati awọn ẹda alãye wọnni si fi ogo ati ọlá, ati ọpẹ́ fun ẹniti o joko lori itẹ́, ti o mbẹ lãye lai ati lailai,

10 Awọn alàgba mẹrinlelogun na wolẹ niwaju ẹniti o joko lori itẹ́, nwọn si tẹriba fun ẹniti mbẹ lãye lai ati lailai, nwọn si fi ade wọn lelẹ niwaju itẹ́ na, wipe,

11 Oluwa, iwọ li o yẹ lati gbà ogo ati ọlá ati agbara: nitoripe iwọ li o dá ohun gbogbo, ati nitori wiwù rẹ ni nwọn fi wà ti a si ṣe dá wọn.

## ORI 5.

MO si ri li ọwọ́ ọtún ẹniti o joko lori itẹ́ na, iwe kan ti a kọ ninu ati lẹhin, ti a si fi èdidi meje dí.

2 Mo si ri angeli kan alagbara, o nfi ohùn rara ke pe, Tali o yẹ lati ṣí iwe na, ati tabi lati tú èdidi rẹ̀?

3 Kò si si ẹnikan li ọrun, tabi lori ilẹ aiye, tabi nisalẹ ilẹ, ti o le ṣí iwe na, tabi ti o le wò inu rẹ̀.

4 Emi si sọkun gidigidi, nitoriti a kò ri ẹnikan ti o yẹ lati ṣí ati lati kà iwe na, tabi lati wò inu rẹ̀.

5 Ọkan ninu awọn alàgba na si wi fun mi pe, Máṣe sọkun mọ́: kiyesi i, Kiniun ẹ̀ya Juda, Gbòngbo Dafidi, ti ṣẹgun lati ṣí iwe na, ati lati tú èdidi rẹ̀ mejeje.

6 Mo si wò, si kiyesi i, li arin itẹ́ na, ati ti awọn ẹda alãye mẹrin na, ati li arin awọn alàgba na, Ọdọ-Agutan kan duro, o dabi ẹnipe ati pa a, o ni iwo meje ati oju meje, ti iṣe Ẹmí meje ti Ọlọrun, ti a rán jade lọ si ori ilẹ aiye gbogbo.

7 O si wá o si gbà iwe na li ọwọ́ ọtún ẹniti o joko lori itẹ́ na.

8 Nigbati o si gbà iwe na, awọn ẹda alãye mẹrin na, ati awọn alàgba mẹrinlelogun na wolẹ niwaju Ọdọ-Agutan na, olukuluku nwọn ni dùru ati ìgo wura, ti o kún fun turari, ti o jasi adura awọn enia mimọ́.

9 Nwọn si nkọ orin titun, wipe, Iwọ li

Digitized by Google

o yẹ lati gbà iwe na, ati lati ṣí èdidi rẹ̀:
nitoriti ati pa ọ, iwọ si ti fi ẹ̀jẹ rẹ rà wa
pada si Ọlọrun lati inu ibatan gbogbo, ati
ède gbogbo, ati inu enia gbogbo, ati orilẹ-
ède gbogbo wá;
10 Iwọ si ti fi wa jẹ ọba ati alufa si
Ọlọrun wa: awa o si mã jọba lori ilẹ aiye.
11 Emi si wò, mo si gbọ́ ohùn awọn
angeli pupọ̀ rọgba yi itẹ́ na ká, ati yi awọn
ẹda alãye, ati awọn alàgba na ká: iye wọn
si jẹ igba ẹgbẹ̀run mẹwa ẹgbẹrun mẹwa, ati
ẹgbẹgbẹ̀run-ẹgbẹ̀run;
12 Nwọn nwi li ohùn rara pe, Yiyẹ li
Ọdọ-Agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara,
ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ogo,
ati ibukún.
13 Gbogbo ẹda ti o si mbẹ li ọrun, ati
lori ilẹ aiye, ati nisalẹ ilẹ, ati irú awọn ti
mbẹ ninu okun, ati awọn gbogbo ti mbẹ
ninu wọn, ni mo gbọ́ ti nwipe, Ibukún, ati
ọlá, ati ogo, ati agbara, fun ẹniti o joko lori
itẹ́, ati fun Ọdọ-Agutan na lai ati lailai.
14 Ati awọn ẹda alãye mẹrin nì wipe;
Amin. Ati awọn alàgba mẹrinlelogun nì
wolẹ, nwọn si foribalẹ fun ẹniti mbẹ lãye
lai ati lailai.

## ORI 6.

EMI si ri nigbati Ọdọ-Agutan na ṣí ọkan
ninu èdidi wọnni, mo si gbọ́ bi ẹnipe
sisán ãrá, ọkan ninu awọn ẹda alãye mẹrin
nì nwipe, Wá wò o.
2 Mo si ri, si kiyesi i, ẹṣin funfun kan:
ẹniti o si joko lori rẹ̀ ni ọrun kan; a si fi
ade kan fun u: o si jade lọ lati iṣẹgun de
iṣẹgun.
3 Nigbati o si ṣí èdidi keji, mo gbọ́ ohùn
ẹda alãye keji nwipe, Wá wò o.
4 Ẹṣin miran kan si jade, ti o ṣe pupa:
a si fi agbara fun ẹniti o joko lori rẹ̀, lati
gbà alafia kuro lori ilẹ aiye, ati pe ki nwọn
ki o mã pa ara wọn: a si fi idà nla kan le
e lọwọ.
5 Nigbati o si ṣí èdidi kẹta, mo gbọ́
ohùn ẹda alãye kẹta nwipe, Wá wò o.
Mo si wò, si kiyesi i, ẹṣin dúdu kan;
ẹniti o joko lori rẹ̀ ni awẹ-meji oṣuwọn li
ọwọ́ rẹ̀.
6 Mo si gbọ́ ohùn kan li arin awọn ẹda
alãye mẹrẹrin nì nwipe, Oṣuwọn alikama
kan fun owo idẹ kan, ati oṣuwọn ọkà barle
mẹta fun owo idẹ kan; si kiyesi i, ki o má
si ṣe pa oróro ati ọti-waini lara.
7 Nigbati o si ṣí èdidi kẹrin, mo gbọ́
ohùn ẹda alãye kẹrin nwipe, Wá wò o.
8 Mo si wò, si kiyesi i, ẹṣin rọndọn-
rọndọn kan: orukọ ẹniti o joko lori rẹ̀ ni
Ikú, ati Ipò-okú si tọ̀ ọ lẹhin. A si fi
agbara fun wọn lori idamẹrin aiye, lati fi
idà, ati ebi, ati ikú, ati ẹranko ori ilẹ aiye
pa.
9 *Nigbati o si ṣí èdidi karun, mo ri
labẹ pẹpẹ, ọkàn awọn ti a ti pa nitori ọ̀rọ
Ọlọrun, ati nitori ẹrí ti nwọn dìmu:
10 Nwọn si kigbe li ohùn rara, wipe,
Yio ti pẹ to, Oluwa, ẹni mimọ́ ati olõtọ,
iwọ kò ṣe idajọ, iwọ kò si gbẹsan ẹ̀jẹ wa
mọ́ lara awọn ti ngbé ori ilẹ aiye?
11 A si fi aṣọ igunwa funfun fun gbogbo
wọn; a si wi fun wọn pe, ki nwọn ki o
simi di ìgba diẹ na, titi awọn ẹlẹgbẹ wọn
iranṣẹ, ati awọn arakọnrin wọn pẹlu, ti a
o pa bi nwọn, yio fi pé.
12 Mo si wò nigbati o ṣí èdidi kẹfa, si
kiyesi i, ìṣẹlẹ nla sẹ̀; õrùn si di dúdu bi
aṣọ-àpo irun, oṣupa si dabi ẹ̀jẹ;
13 Awọn irawọ oju ọrun si ṣubu lù ilẹ,
gẹgẹ bi igi ọpọtọ iti rẹ̀ àigbó eso rẹ̀ dànu,
nigbati a ba ti ọwọ́ ẹfũfu nla mì i.
14 A si ká ọrun kuro bi iwe kiká nigbati
a ba ká a; ati olukuluku òkenla, ati ere-
kuṣu li a si ṣí ni idi kuro ni ipò wọn.
15 Ati awọn ọba aiye, ati awọn ọlọlá,
ati awọn ọlọrọ̀, ati awọn olori ogun, ati
awọn alagbara, ati olukuluku ẹrú, ati olu-
kuluku omnira enia, nwọn fi ara wọn pamọ́
ninu ihò ilẹ, ati ninu ihò okuta ori òkenla;
16 Nwọn si nwi fun awọn òkenla ati
àpata pe, Wólu wa, ki ẹ si pa wa mọ́ kuro
loju ẹniti o joko lori itẹ́, ati kuro ninu
ibinu Ọdọ-Agutan:
17 Nitori ọjọ nla ibinu rẹ̀ de; tani yio
si le duro?

## ORI 7.

LẸHIN nkan wọnyi ni mo ri awọn angeli
mẹrin duro ni igun mẹrẹrin ilẹ aiye,
nwọn di afẹfẹ mẹrẹrin ilẹ aiye mu, ki afẹfẹ
ki o máṣe fẹ́ sori ilẹ aiye, tabi si okun, tabi
si igikigi.
2 Mo si ri angeli miran kan o nti ìha
ìla-õrùn jade wá, o ni èdidi Ọlọrun alãye
lọwọ: o si kigbe li ohùn rara si awọn
angeli mẹrin, ti a fifun lati pa ilẹ aiye ati
okun lara,
3 Wipe, Máṣe pa ilẹ aiye, tabi okun,
tabi igi lara, titi awa o fi fi èdidi sami si
awọn iranṣẹ Ọlọrun wa ni iwaju wọn.
4 Mo si gbọ́ iye awọn ẹniti a fi èdidi
sami si: awọn ti a sami si jẹ ọkẹ meje o le
ẹgbaji lati inu awọn ẹ̀ya awọn ọmọ Israeli
gbogbo wá.

Digitized by Google

5 Ninu ẹya Juda a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa. Ninu ẹya Reubeni a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa. Ninu ẹya Gadi a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa.
6 Ninu ẹya Aṣeri a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa. Ninu ẹya Neftalimu a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa. Ninu ẹya Manasse a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa.
7 Ninu ẹya Simeoni a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa. Ninu ẹya Lefi a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa. Ninu ẹya Issakari a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa.
8 Ninu ẹya Sebuloni a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa. Ninu ẹya Josefu a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa. Ninu ẹya Benjamini a fi èdidi sami si ẹgbã mẹfa.
9 Lẹhin eyi mo wò, si kiyesi i, ọ̀pọlọpọ enia, ti ẹnikẹni kò le kaye, lati inu orilẹ-ède gbogbo, ati ibatan, ati enia, ati lati inu ède gbogbo wá, nwọn duro niwaju itẹ́, ati niwaju Ọdọ-Agutan na, a wọ̀ wọn li aṣọ igunwa funfun, imọ̀ ọpẹ si mbẹ li ọwọ́ wọn;
10 Nwọn si kigbe li ohùn rara, wipe, Igbala ni fun Ọlọrun wa ti o joko lori itẹ́, ati fun Ọdọ-Agutan.
11 Gbogbo awọn angeli si duro rọgba yi itẹ́ na ká, ati yi awọn alàgba ati awọn ẹda alãye mẹrin na ká, nwọn si wolẹ dojubolẹ niwaju itẹ́, nwọn si sìn Ọlọrun,
12 Wipe, Amin: Ibukún, ati ogo, ati ọgbọ́n, ati ọpẹ́, ati ọlá, ati agbara, ati ipá, fun Ọlọrun wa lai ati lailai. Amin.
13 Ọkan ninu awọn alàgba dahùn, o bi mi pe, Tali awọn wọnyi ti a wọ̀ li aṣọ igunwa àla nì? ati nibo ni nwọn ti wá?
14 Emi si wi fun u pe, Alàgba, Iwọ li o le mọ̀. O si wi fun mi pe, Awọn wọnyi li o ti inu ipọnju nla jade wá, ti nwọn si fọ̀ aṣọ igunwa wọn, ti nwọn si sọ wọn di funfun ninu ẹ̀jẹ Ọdọ-Agutan.
15 Nitorina ni nwọn ṣe mbẹ niwaju itẹ́ Ọlọrun, ati ti nwọn sìn i li ọsán ati li oru ninu tempili rẹ̀: ẹniti o si joko lori itẹ́ ni yio ṣiji bò wọn.
16 Ebi kì yio si pa wọn mọ́, bẹ̃li ongbẹ kì yio si gbẹ wọn mọ́; bẹ̃li õrùn kì yio si ràn mọlẹ si wọn mọ́, tabi orukoru.
17 Nitori Ọdọ-Agutan ti o mbẹ li arin itẹ́ ni yio mã bọ́ wọn, yio si mã sìn wọn lọ si ibi orisun omi iyè: Ọlọrun yio si nù omije gbogbo nù kuro li oju wọn.

## ORI 8.

NIGBATI o si ṣí èdidi keje, kẹ́kẹ́ pa li ọrun niwọn àbọ wakati kan.
2 Mo si ri awọn angeli meje ti nwọn duro niwaju Ọlọrun; awọn li a si fi ipè meje fun.
3 Angeli miran kan si wá, o si duro ti pẹpẹ, o ni awo turari wura kan; a si fi turari pupọ̀ fun u, ki o le fi i kún adura awọn enia mimọ́ gbogbo, lori pẹpẹ wura ti mbẹ niwaju itẹ́.
4 Ati ẽfin turari na pẹlu adura awọn enia mimọ́ gòke lọ siwaju Ọlọrun lati ọwọ́ angeli na wá.
5 Angeli na si mu awo turari na, o si fọ̀n iná ori pẹpẹ kun inu rẹ̀, o si mu u wá si ilẹ aiye: ohùn, ati ãrá, ati mànamána, ati ìṣẹlẹ si mbẹ.
6 Awọn angeli meje ti nwọn ni ipè meje mura ati fun.
7 Angeli ikini fun, yinyín ati iná ti o dàpọ pẹlu ẹ̀jẹ jade, a si wọ́ wọn jù sori ilẹ aiye: idamẹta ilẹ aiye si jona, idamẹta igi si jóna, ati gbogbo koriko tutù jóna.
8 Angeli keji si fun, a si wọ́ òkenla ti o dabi ẹnipe iná nsun jù sinu okun: idamẹta okun si di ẹ̀jẹ;
9 Ati idamẹta ẹda ti mbẹ ninu okun, ti o ni ẹmí si kú; ati idamẹta ọkọ̀ si bajẹ.
10 Angeli kẹta si fun, irawọ nla kan si bọ́ ti ọrun wá, o njó bi fitila, o si ṣubu lù idamẹta odònla, ati lù orisun omi;
11 A si mã pè orukọ irawọ na ni Kikorò: idamẹta omi si di kikorò; ọ̀pọlọpọ enia li o si kú nipa omi wọnni, nitoriti a sọ nwọn di kikorò.
12 Angeli kẹrin si fun, a si lù idamẹta õrùn, ati idamẹta oṣupa, ati idamẹta awọn irawọ; bẹ̃ni idamẹta wọn di ṣíṣu, ọjọ kò si fi idamẹta rẹ̀ mọlẹ, ati oru pẹlu.
13 Mo si wò, mo si gbọ́ idì kan nfò là arin ọrun lọ, o nwi li ohùn rara pe, Egbé, egbé, egbé, fun awọn araiye nitori ohùn ipè ti awọn angeli mẹta iyokù, ti o ni fun si i!

## ORI 9.

ANGELI karun si fun, mo si ri irawọ kan bọ́ lati ọrun wá si ilẹ: on li a si fi ọmọ-ṣika ọgbun ainisalẹ fun.
2 O si ṣí ọgbun ainisalẹ na; ẽfin si ru jade lati inu ọgbun na wá, bi ẽfin ileru nla; ati õrùn ati oju sanma si ṣú nitori ẽfin ọgbun na.
3 Eṣú si jade ti inu ẽfin na wá sori ilẹ: awọn li a si fi agbara fun, bi akẽkẽ ilẹ ti li agbara.
4 A si fi aṣẹ fun wọn pe ki nwọn ki o máṣe pa koriko ilẹ, tabi ohun tutù kan

Digitized by Google

tabi igikigi kan lara; bikoṣe kìki awọn
enia ti kò ni àmi èdidi Ọlọrun ni iwaju
wọn.
5 Awọn li a si fifun pe ki nwọn ki o
máṣe pa wọn, bikoṣe pe ki a dá wọn li oró
li oṣù marun: oró wọn si dabi oró akẽkẽ,
nigbati o ba ta enia.
6 Li ọjọ wọnni li awọn enia yio si mã
wá ikú, nwọn kì yio si ri i; nwọn o si fẹ
ikú, ikú yio si sá kuro lọdọ wọn.
7 Iwo awọn eṣú na dabi awọn ẹṣin ti a
mura silẹ fun ogun; ati li ori wọn a ri o
dabi ade wura, oju wọn si dabi oju enia;
8 Nwọn si ni irun bi irun obirin, ehin
wọn si dabi ehin kiniun.
9 Nwọn si ni awo ìgbàiya, bi awo ìgbà-
iya irin; iró iyẹ́ wọn si dabi iró kẹkẹ́ ẹṣin
pupọ̀ ti nsure lọ si ogun.
10 Nwọn si ni ìru bi ti akẽkẽ, tita si
mbẹ ni ìru wọn: agbara wọn ni ati pa ara-
iye lara li oṣù marun.
11 Nwọn si ni ọba kan lori wọn, ti iṣe
angeli ọgbun ainisalẹ, orukọ ẹniti ijẹ Abad-
doni li ède Heberu, ṣugbọn li ède Hellene
orukọ rẹ̀ ama jẹ Apollioni.
12 Egbé kan kọja; si kiyesi i, egbé
meji si mbọ̀wa lẹhin eyi.
13 Angeli kẹfa si fun, mo si gbọ́ ohùn
lati ibi iwo mẹrin ti ibi pẹpẹ wura jade wá,
ti mbẹ niwaju Ọlọrun,
14 Nwi fun angeli kẹfa na ti o ni ipè na
pe, Tú awọn angeli mẹrin nì silẹ ti a dè
ninu odònla Eufrate.
15 A si tú awọn angeli na silẹ, ti a pese
tẹlẹ fun wakati na, ati ọjọ kan, ati oṣù
kan, ati ọdun kan, lati pa idamẹta enia.
16 Iye ogun awọn ẹlẹṣin si jẹ ẹgbã ma-
run ọkẹ́: mo si gbọ́ iye wọn.
17 Bayi ni mo si ri awọn ẹṣin na li oju-
ran, ati awọn ti o gùn wọn, nwọn ni awo
ìgbaiya iná, ati ti jakinti, ati ti sulfuru
(okuta iná): ori awọn ẹṣin na si dabi ori
awọn kiniun; ati lati ẹnu wọn ni iná, ati
ẽfin, ati sulfuru ti njade wá.
18 Lati ipa ohun mẹta wọnyi li a pa
idamẹta enia, nipa iná, ati nipa ẽfin, ati
nipa sulfuru ti o nti ẹnu wọn jade wá.
19 Nitoripe agbara wọn mbẹ li ẹnu wọn,
ati ni ìru wọn: nitoripe ìru wọn dabi ejò,
o si ni ori, wọnni ni nwọn fi npani lara.
20 Awọn enia iyokù ti a kò si ti ipa
iyọnu wọnyi pa, kò si ronupiwada iṣẹ ọwọ́
wọn, pe ki nwọn ki o máṣe sìn awọn ẹmi
èṣu, ati ere wura mọ́, ati ti fadaka, ati ti
idẹ, ati ti okuta, ati ti igi: ti kò le riran,
ti kò je gbọ́, tabi ti kò le rìn:
21 Bẽni nwọn kò ronupiwada enia pipa
wọn, tabi oṣó wọn, tabi àgbere wọn, tabi
olè wọn.

## ORI 10.

MO si ri angeli miran kan alagbara, o ti
ọrun sọkalẹ wá, a fi awọsanma wọ̀ ọ
li aṣọ: oṣumare kan si mbẹ li ori rẹ̀, oju rẹ̀
si dabi õrùn, ati ẹsẹ rẹ̀ bi ọwọ̀n iná:
2 O si ni iwe kekere kan li ọwọ́ rẹ̀ ti o
ṣí: o si fi ẹsẹ rẹ̀ ọtún tẹ̀ okun, ati ẹsẹ rẹ̀
òsi tẹ̀ ilẹ gbigbẹ,
3 O si ke li ohùn rara, bi igbati kiniun
ba bú ramuramu: nigbati o si ké, ãrá meje
fi ohùn wọn sán.
4 Nigbati ãrá meje fi ohùn wọn sán nì,
mo mura ati kọwe: mo si gbọ́ ohùn lati
ọrun wá nwi fun mi pe, Fi èdidi dí ohun ti
awọn ãrá mejeje nì fi sisán sọ, má si ṣe
kọwe wọn.
5 Angeli ti mo si ri ti o duro ninu okun
ati lori ilẹ gbigbẹ, o gbé ọwọ́ rẹ̀ si oke
ọrun,
6 O si fi ẹniti mbẹ lãye lai ati lailai
búra, ẹniti o dá ọrun, ati ohun ti mbẹ ninu
rẹ̀, ati ilẹ aiye, ati ohun ti mbẹ ninu rẹ̀,
ati okun, ati ohun ti mbẹ ninu rẹ̀, pe ìgba
kì yio si mọ́:
7 Ṣugbọn li ọjọ ohùn angeli keje, nigba-
ti o ba bẹ̀rẹ si ifun, a o pari ohun ijinlẹ
Ọlọrun, bi ati sọ fun awọn woli iranṣẹ rẹ̀.
8 Ohùn na ti mo si gbọ́ lati ọrun wá tún
sọ fun mi, o si wipe, Lọ igbà iwe kekere ti
o ṣí silẹ li ọwọ́ angeli nì, ti o duro ninu
okun ati lori ilẹ gbigbẹ.
9 Mo si tọ̀ angeli na lọ, mo si wi fun u
pe, Fun mi ni iwe kekere nì. O si wi fun
mi pe, Gbà a, si mu u jẹ; yio si mu inu rẹ
korò, ṣugbọn yio dùn li ẹnu rẹ bi oyin.
10 Mo si gbà iwe kekere na li ọwọ́ angeli
na, mo si jẹ ẹ; o si dùn li ẹnu mi bi oyin:
bi mo si ti jẹ ẹ tan, inu mi korò.
11 O si wi fun mi pe, Iwọ o tún sọtẹlẹ
niwaju enia pupọ̀, ati orilẹ-ède, ati ède,
ati ọba pupọ̀.

## ORI 11.

A SI fi ifefe kan fun mi o dabi ọpá ìwọn:
angeli na si duro, nwipe, Dide, si di-
wọ̀n tempili Ọlọrun, ati pẹpẹ, ati awọn ti
nsìn ninu rẹ̀.
2 Ṣugbọn fi agbala ti mbẹ lode tempili
silẹ, má si ṣe diwọ̀n rẹ̀; nitoriti a fi i fun
awọn Keferi: ilu mimọ́ nì li a o si fi ẹsẹ tẹ̀
mọlẹ li ogoji oṣù o le meji.
3 Emi o si fi agbara fun awọn ẹlẹri mi

Digitized by Google

mejeji, nwọn o si mã sọtẹlẹ ni ẹgbẹfa ọjọ o le ọgọta, ni wiwọ̀ aṣọ-àpo.
4 Wọnyi ni igi oróro meji nì, ati ọpá fitila meji nì, ti o duro niwaju Ọlọrun aiye.
5 Bi ẹnikẹni o ba si pa wọn lara, iná ti ẹnu wọn jade wá, o si pa awọn ọtá wọn run: bi ẹnikẹni o ba si pa wọn lara, bayi li a o pa a.
6 Awọn wọnyi li o ni agbara lati sé ọrun, ki o máṣe rọ̀jo li ọjọ asọtẹlẹ wọn: nwọn si ni agbara lori omi lati sọ wọn di ẹ̀jẹ, ati lati fi iyọnu gbogbo lù aiye, nigbakugba ti nwọn ba fẹ.
7 Nigbati nwọn ba si ti jẹ ẹrí wọn tan, ẹranko ti o nti inu ọgbun ainisalẹ jade wá ni yio ba wọn jagun, yio si ṣẹgun wọn, yio si pa wọn.
8 Okú wọn yio si sùn ni igboro ilunla nì, ti a npè nipa ti ẹmí ni Sodomu ati Egipti, nibiti a gbé kàn Oluwa wa mọ agbelebu.
9 Ati awọn ti inu awọn enia, ati ti awọn ibatan, ati ède, ati orilẹ-ède, yio mã ri okú wọn ni ijọ mẹta on àbọ, nwọn kì yio si jẹ ki a gbé okú wọn sinu isà okú.
10 Ati awọn ti o ngbé ori ilẹ aiye yio si yọ̀ si wọn lori, nwọn o si ṣe inu didùn, nwọn o si ta ara wọn lọrẹ; nitoriti awọn woli mejeji yi dá awọn ti o mbẹ lori ilẹ aiye loró.
11 Ati lẹhin ijọ mẹta on àbọ ẹmí ìye lati ọdọ Ọlọrun wá wọ̀ inu wọn lọ, nwọn si dide duro li ẹsẹ wọn; ẹ̀ru nla si ba awọn ti o ri wọn.
12 Nwọn si gbọ́ ohùn nla kan lati ọrun wá nwi fun wọn pe, Ẹ gòke wá ìhin. Nwọn si gòke lọ si ọrun ninu awọsanma; awọn ọtá wọn si nwò wọn.
13 Ni wakati kanna ìsẹlẹ nla kan sẹ̀, idamẹwa ilu nì si wó, ati ninu ìsẹlẹ na ẹdẹgbarin enia li a pa kú: ẹ̀ru si ba awọn iyokù, nwọn si fi ogo fun Ọlọrun ọrun.
14 Egbé keji kọja; si kiyesi i, egbé kẹta si mbọ̀wa kánkán.
15 Angeli keje si fun; a si gbọ́ ohùn nla lati ọrun wá, nwipe, Awọn ijọba aiye yi di ijọba ti Oluwa wa, ati ti Kristi rẹ̀; on o si ma jọba lai ati lailai.
16 Awọn alàgba mẹrinlelogun nì, ti o joko niwaju Ọlọrun ni ibujoko wọn, wolẹ dojubolẹ, nwọn si sìn Ọlọrun,
17 Wipe, Awa fi ọpẹ́ fun ọ, Oluwa Ọlọrun Olodumare, iwọ ti mbẹ, ti o ti wà, ti yio si ma bọ̀wa; nitoriti iwọ ti gbà agbara nla rẹ, iwọ si ti jọba.
18 Inu si bi awọn orilẹ-ède, ibinu rẹ si de, ati ìgba awọn okú, ti a o dá wọn li ẹjọ, ati ti iwọ o fi ẹ̀bun fun awọn woli awọn iranṣẹ rẹ, ati fun awọn enia mimọ́, ati fun awọn ti o bẹ̀ru orukọ rẹ, ati ewe ati àgba; ati ti iwọ o run awọn ti npa aiye run.
19 A si ṣí tempili Ọlọrun silẹ li ọrun, a si ri apoti majẹmu ninu tempili rẹ̀: mànamána si mbẹ, ati ohùn, ati ãrá, ati ìsẹlẹ, ati yinyín nla.

## ORI 12.

ÀMI nla kan si hàn li ọrun; a fi õrùn wọ̀ obirin kan li aṣọ, oṣupa si mbẹ li atẹlẹsẹ rẹ̀, ade irawọ mejila si mbẹ li ori rẹ̀:
2 Bi o si ti lóyun o kigbe o nrọbi, o si wà ni irora ati bí.
3 Àmi miran kan si tún hàn li ọrun; si kiyesi i, dragoni kan pupa nla, ti o ni ori meje ati iwo mẹwa, ade meje si mbẹ li ori rẹ̀.
4 Ìru rẹ̀ si nfà ida kẹta irawọ ọrun, o nwọ́ wọn jù silẹ: dragoni na si duro niwaju obirin na ti o mura ati bímọ, lati pa ọmọ rẹ̀ jẹ li ojukanna ti a bí i.
5 O si bí ọmọkọnrin kan, ẹniti yio mã fi ọpá irin mu awọn orilẹ-ède gbogbo sìn: a si gbà ọmọ na lọ si ọdọ Ọlọrun, ati si ori itẹ́ rẹ̀.
6 Obirin na si sá lọ si aginjù, nibiti a gbé ti pèse àye silẹ dè e lati ọwọ́ Ọlọrun wá, pe ki nwọn ki o mã bọ́ ọ nibẹ̀ li ẹgbẹfa ọjọ o le ọgọta.
7 Ogun si mbẹ li ọrun: Mikaeli pẹlu awọn angeli rẹ̀ mba dragoni na jà; dragoni si jà ati awọn angeli rẹ̀.
8 Nwọn kò si le ṣẹgun; bẹ̃ni kò si àye fun wọn mọ́ li ọrun.
9 A si lé dragoni nla na jade, ejò lailai nì, ti a npè ni Èṣu, ati Satani, ti ntàn gbogbo araiye jẹ: a si lè e jù si ilẹ aiye, a si le awọn angeli rẹ̀ jade pẹlu rẹ̀.
10 Mo si gbọ́ ohùn rara li ọrun, nwipe, Nigbayi ni igbala de, ati agbara, ati ijọba Ọlọrun wa, ati agbara ti Kristi rẹ̀; nitori a lé olufisùn awọn arakọnrin wa sọkalẹ, ti o nfi wọn sùn niwaju Ọlọrun wa lọsán ati loru.
11 Nwọn si fi ẹ̀jẹ Ọdọ-Agutan, ati ọ̀rọ ẹrí wọn ṣẹgun rẹ̀; nwọn kò si fẹ ẹmí wọn titi de ikú.
12 Nitorina ẹ mã yọ̀, ẹnyin ọrun, ati ẹnyin ti ngbé inu wọn. Egbé ni fun awọn araiye, ati fun awọn ará inu okun! nitori Èṣu sọkalẹ tọ̀ nyin wá, ti o ni ibinu nla, nitori o mọ̀ pe kìki ìgba kukuru li on ni.

Digitized by Google

13 Nigbati dragoni na ri pe a lé on lọ si
ilẹ aiye, o ṣe inunibini si obirin ti o bí
ọmọkọnrin na.
14 A si fi apá iyẹ́ meji ti idì nla kan
fun obirin na, pe ki o fò lọ si aginjù, si ipò
rẹ̀, nibiti a gbé mbọ́ ọ nigba kan, ati ìgba
ìgba, ati àbọ ìgba, kuro loju ejò na.
15 Ejò na si fọ́n omi jade lati ẹnu rẹ̀ wá
lẹhin obirin na bi odo ṣìṣan nla, ki o le mu
ìṣan omi na gbá obirin na lọ.
16 Ilẹ si ràn obirin na lọwọ, ilẹ si yà
ẹnu rẹ̀, o si mu ìṣan omi na, ti dragoni na
fọ́n jade lati ẹnu rẹ̀ wá.
17 Dragoni na si binu gidigidi si obirin
na, o si lọ iba awọn ọmọ rẹ̀ iyokù jagun, ti
npa ofin Ọlọrun mọ́, ti o si ni ẹrí Jesu Kristi.

## ORI 13.

MO si duro lori iyanrìn okun, mo si ri
ẹranko kan o ti inu okun jade wá, o
ni ori meje ati iwo mẹwa, ati lori iwo rẹ̀
ade mẹwa, ati li ori rẹ̀ wọnni orukọ ọ̀rọ òdi
si Ọlọrun.
2 Ẹranko ti mo ri na si dabi ẹkùn, ẹsẹ
rẹ̀ si dabi ẹsẹ beari, ẹnu rẹ̀ si dabi ẹnu ki-
niun: dragoni na si fun u li agbara rẹ̀, ati
ibujoko rẹ̀, ati ọlá nla.
3 Mo si ri ori rẹ̀ kan o dabi ẹnipe a ṣá a
lọgbẹ aṣápa; ọgbẹ aṣápa yi si jiná: ẹnu si
yà gbogbo araiye si ẹranko na.
4 Nwọn si foribalẹ fun dragoni na ti o fi
agbara fun ẹranko na yi: nwọn si foribalẹ
fun ẹranko na, wipe, Tali o dabi ẹranko
yi? tali o le ba a jagun?
5 A si fi ẹnu fun u o nsọ̀rọ ohun nla ati
ọ̀rọ òdi si Ọlọrun; a si fi agbara fun u lati
duro ni ogoji oṣù o le meji.
6 O si yà ẹnu rẹ̀ ninu ọ̀rọ òdi si Ọlọrun,
lati sọ̀rọ òdi si orukọ rẹ̀, ati si agọ́ rẹ̀, ati
si awọn ti mbẹ li ọrun.
7 A si fifun u lati mã ba awọn enia mi-
mọ́ jagun, ati lati ṣẹgun wọn: a si fi agba-
ra fun u lori gbogbo ìbatan, ati èdè, ati
orilẹ-èdè.
8 Gbogbo awọn ti mbẹ lori ilẹ aiye yio
si mã foribalẹ fun u, orukọ awọn ẹniti a kò
kọ sinu iwe ìye Ọdọ-Agutan ti a ti pa lati
ipilẹṣẹ aiye.
9 Bi ẹnikan ba li etí ki o gbọ́.
10 Ẹniti o ndini lọ ni igbekun yio si lọ
sinu igbèkun: ẹniti o nfi idà pani li a o si
fi idà pa. Nihinyi ni sũru ati igbagbọ́
awọn enia mimọ́ gbé wà.
11 Mo si ri ẹranko miran kan o njade ti
inu ilẹ wá; o si ni iwo meji bi ọdọ-agutan,
o si nsọ̀rọ bi dragoni.
12 O si nlò gbogbo agbara ẹranko ti iṣa-
ju loju rẹ̀, o si mu ilẹ aiye ati awọn ti mbẹ
ninu rẹ̀ foribalẹ fun ẹranko iṣaju, ti ọgbẹ
aṣápa rẹ̀ jiná.
13 O si nṣe iṣẹ iyanu nla, bẹ̃li o si mu ki
iná ki o ti ọrun wá si ilẹ aiye li oju awọn
enia,
14 O si ntàn awọn ti mbẹ li aiye jẹ,
nipa iṣẹ iyanu wọnyi ti o ni agbara lati ṣe
niwaju ẹranko na; o nwi fun awọn ti mbẹ
lori ilẹ aiye, pe ki nwọn ki o lọ iyá aworan
ẹranko na, ti o ti gbà ọgbẹ nipa idà, ti o
si yè.
15 O si ni agbara lati fi ẹmí fun aworan
ẹranko na, pe ki aworan ẹranko na ki o mã
sọ̀rọ, ki o si mu ki iye awọn ti kò fẹ fori-
balẹ fun aworan ẹranko na ki a pa wọn.
16 O si mu gbogbo wọn, ati kekere ati
àgba, ọlọ̀rọ̀ ati talakà, omnira ati ẹrú, ki a
fi àmi kan fun wọn li ọwọ́ ọtún wọn, tabi
ni iwaju wọn:
17 Ati pe ẹnikẹni kò gbọdọ rà tabi ki o
tà, bikoṣe awọn ti o ni àmi, tabi orukọ
ẹranko na, tabi iye orukọ rẹ̀.
18 Nihinyi li ọgbọ́n gbé wà. Ki ẹniti o
ni ọgbọ́n, ki o kà iye ẹranko na: nitoripe
iye enia kan ni; iye rẹ̀ si jẹ ẹgbẹta o le
ọgọta o le mẹfa.

## ORI 14.

MO si wò, kiyesi i, Ọdọ-Agutan kan duro
lori òke Sioni, ati pẹlu rẹ̀ ọkẹ́ meje o
le ẹgbaji enia, nwọn ni orukọ Baba rẹ̀ ti a
kọ si iwaju wọn.
2 Mo si gbọ́ ohùn kan lati ọrun wá, bi
iró omi pupọ̀, ati bi sisán ãrá nla: mo si
gbọ́ ohùn awọn aludùru, nwọn nlù dùru
wọn:
3 Nwọn si nkọ bi ẹnipe orin titun ni-
waju itẹ́ nì, ati niwaju awọn ẹda alãye mẹ-
rin nì, ati awọn alàgba nì: ko si si ẹniti o
le kọ́ orin na, bikoṣe awọn ọkẹ́ meje o le
ẹgbaji enia, ti a rà pada lori ilẹ aiye.
4 Awọn wọnyi li a kò fi obirin sọdi ẽri;
nitoripe wundia ni nwọn. Awọn wọnyi ni
ntọ̀ Ọdọ-Agutan lẹhin nibikibi ti nrè.
Awọn wọnyi li a ràpada ninu awọn enia,
nwọn jẹ́ eso akọso fun Ọlọrun ati fun Ọdọ-
Agutan.
5 A kò si ri ẹ̀tan li ẹnu wọn: nitori
nwọn wà li ailẹṣẹ niwaju itẹ́ Ọlọrun.
6 Mo si ri angeli miran kan nfò li arin
ọrun, o ni Ihin-rere ainipẹkun lọwọ lati
wasu fun awọn ti o ngbé ori ilẹ aiye, ati
fun orilẹ-èdè, ati ibatan, ati èdè, ati enia
gbogbo,

Digitized by Google

7 O nwi li ohùn rara pe, Ẹ bẹ̀ru Ọlọrun,
ki ẹ si fi ogo fun u ; nitoriti wakati idajọ
rẹ̀ de : ẹ si foribalẹ fun ẹniti o dá ọrun, on
aiye, ati okun, ati awọn orisun omi.
8 Angeli miran kan si tẹ̀le e, o nwipe,
Babiloni wó, Babiloni wó, ilunla nì, nitoriti
o mu orilẹ-ède gbogbo mu ninu ọti-waini
ibinu àgbere rẹ̀.
9 Angeli kẹta si tẹ̀le e, nwi li ohùn rara
pe, Bi ẹnikẹni ba nforibalẹ fun ẹranko nì,
ati aworan rẹ̀, ti o si gbà àmi rẹ̀ ni iwaju
rẹ̀, tabi li ọwọ́ rẹ̀,
10 On na ni yio mu ninu ọti-waini ibinu
Ọlọrun, ti a tú jade li aini àbula sinu ago
irunu rẹ̀ ; a o si fi iná ati sulfuru ṣẹ́ ẹ nisẹ
oró niwaju awọn angeli mimọ́, ati niwaju
Ọdọ-Agutan :
11 Ẹfin ìṣẹ oró wọn si ru lọ soke lai ati
lailai : isimi kò si si lọsán ati loru fun
awọn ti nforibalẹ fun ẹranko na ati aworan
rẹ̀, ati ẹnikẹni ti o si gbà àmi orukọ
rẹ̀,
12 Nihinyi ni sũru awọn enia mimọ́ gbé
wà : awọn ti npa ofin Ọlọrun ati igbagbọ́
Jesu mọ́ li eyi.
13 Mo si gbọ́ ohùn kan lati ọrun wá nwi
fun mi pe, Kọwe, Alabukún fun li awọn
okú ti o kú nipa ti Oluwa lati ìhin lọ :
Nitõtọ, li Ẹmí wi, ki nwọn o le simi
kuro ninu lãlã wọn ; iṣẹ wọn si ntọ̀ wọn
lẹhin.
14 Mo si wò, si kiyesi i, awọsanma funfun,
ati lori awọsanma na ẹnikan joko bi
Ọmọ enia, o ni ade wura li ori rẹ̀, ati doje
mimu li ọwọ́ rẹ̀.
15 Angeli miran kan si ti inu tempili
jade wá, nke li ohùn rara si ẹniti o joko
lori awọsanma pe, Tẹ̀ doje rẹ bọ̀ ọ, ki o si
ma rẹ́-kà : nitori ti akokò de fun ọ lati ma
rẹ́-kà ; nitoriti ikorè aiye gbó tan.
16 Ẹniti o si joko lori awọsanma si tẹ̀
doje rẹ̀ bọ̀ ori ilẹ aiye ; a si rẹ́-kà aiye.
17 Angeli miran kan si ti inu tempili
jade wá ti mbẹ li ọrun, on pẹlu si ni doje
mimu.
18 Angeli miran kan si ti ibi pẹpẹ jade
wá, ti o ni agbara lori iná ; o si ke li ohùn
rara si ẹniti o ni doje mimu, wipe, Tẹ̀ doje
rẹ mimu bọ̀ ọ, ki o si kó ṣiri odidi eso ajara
ori ilẹ aiye jọ ; nitoriti eso rẹ̀ pọ́n.
19 Angeli na si tẹ̀ doje rẹ̀ bọ̀ ori ilẹ aiye,
o si kó eso ajara ori ilẹ aiye jọ, o si kó o lọ
sinu ifúnti, ifúnti nla ibinu Ọlọrun.
20 A si tẹ̀ ifúnti na lẹhin ode ilunla nì,
ẹ̀jẹ si ti inu ifúnti na ta jade, ani de okùn
ijanu ẹṣin, niwọn ẹgbẹjọ oṣuwọn furlongi.

## ORI 15.

MO si ri àmi miran kan li ọrun, o tobi o
si ṣe iyanu, awọn angeli meje ti o ni
iyọnu ikẹhin meje nì ; nitori ninu wọn li a
gbé kún ibinu Ọlọrun si.
2 Mo si ri bi ẹnipe okun digí ti o dàpọ
pẹlu iná : ati awọn ti nwọn ṣẹgun ẹranko
nì, ati aworan rẹ̀, ati àmi rẹ̀, ati iye orukọ
rẹ̀, nwọn duro lori okun digí yi, nwọn ni
dùru Ọlọrun.
3 Nwọn si nkọ orin ti Mose, iranṣẹ
Ọlọrun, ati orin ti Ọdọ-Agutan, wipe, Nla
ati iyanu ni iṣẹ rẹ, Oluwa Ọlọrun Olodumare ;
ododo ati otitọ li ọ̀na rẹ, iwọ Ọba
awọn enia mimọ́.
4 Tani kì yio bẹ̀ru rẹ, Oluwa, ti kì yio
si fi ogo fun orukọ rẹ ? nitoripe iwọ nikanṣoṣo
ni mimọ́ : nitoripe gbogbo orilẹ-ède
ni yio wá, ti yio si foribalẹ niwaju rẹ ; nitori
a fi idajọ rẹ hàn.
5 Lẹhin eyinì mo si wò, si kiyesi i, a ṣí
tempili agọ́ ẹrí li ọrun silẹ :
6 Awọn angeli meje na si ti inu tempili
jade wá, nwọn ni iyọnu meje nì, a wọ̀ wọn
li aṣọ ọgbọ àla mimọ́, a si fi àmure wura dì
wọn li owokan àiya.
7 Ati ọkan ninu awọn ẹda alãye mẹrin
nì fi ìgo wura meje fun awọn angeli meje
nì, ti o kún fun ibinu Ọlọrun, ẹniti mbẹ
lãye lai ati lailai.
8 Inu tempili si kún fun ẽfin lati inu
ogo Ọlọrun, ati inu agbara rẹ̀ wá ; kò si si
ẹniti o le wọ̀ inu tempili na lọ, titi a o fi
mu iyọnu mejeje awọn angeli meje nì ṣẹ.

## ORI 16.

MO si gbọ́ ohùn nla kan lati inu tempili
jade wá, nwi fun awọn angeli meje nì
pe, Ẹ lọ, ẹ si tú ìgo ibinu Ọlọrun wọnni si
ori ilẹ aiye.
2 Ekini si lọ, o si tú ìgo tirẹ̀ si ori ilẹ
aiye ; ojuju irira ati buburu si dá awọn enia
ti o ni àmi ẹranko nì, ati awọn ti nforibalẹ
fun aworan rẹ̀.
3 Angeli keji si tú ìgo tirẹ̀ sinu okun ; o
si dabi ẹ̀jẹ okú enia : gbogbo ọkàn alãye si
kú ninu okun.
4 Angeli kẹta si tú ìgo tirẹ̀ sinu odò
ṣiṣàn nla, ati si orisun omi ; nwọn si di
ẹ̀jẹ.
5 Mo si gbọ́ angeli ti omi nì wipe, Ọlododo
ni iwọ, Oluwa, ti mbẹ, ti o ti wà, ti
yio si wà, nitoriti iwọ ṣe idajọ bayi.
6 Nitoriti nwọn ti ta ẹ̀jẹ awọn enia mimọ́



Digitized by Google

ati ti awọn woli silẹ, iwọ si fi ẹ̀jẹ fun wọn mu; nitori ti nwọn yẹ.

7 Mo si gbọ́ angeli miran kan lati ibi pẹpẹ wá nwipe, Bẹ̃ni, Oluwa Ọlọrun Olodumare, otitọ ati ododo ni idajọ rẹ.

8 Angeli kẹrin si tú ìgo tirẹ̀ si oju õrùn; a si fi agbara fun u lati fi iná jó enia lara.

9 A si fi oru nla mu enia lara jóna, nwọn si sọ̀rọ ọ̀di si orukọ Ọlọrun, ti o li agbara lori iyọnu wọnyi: nwọn kò si ronupiwada lati fi ogo fun Ọlọrun.

10 Angeli karun si tú ìgo tirẹ̀ sori ibujoko ẹranko nì; ijọba rẹ̀ si kún fun òkunkun; nwọn si ngiri ahọn wọn jẹ nitori irora.

11 Nwọn si sọ̀rọ ọ̀di si Ọlọrun ọrun, nitori irora wọn ati õju wọn, nwọn kò si ronupiwada iṣẹ wọn.

12 Angeli kẹfa si tú ìgo tirẹ̀ si odònla Eufrate; omi inu rẹ̀ si gbẹ, ki ọ̀na awọn ọba ìla-õrùn ki o le ṣí silẹ.

13 Mo si ri awọn ẹmí aimọ́ mẹta, nwọn dabi ọ̀pọlọ́, nwọn ti ẹnu dragoni nì jade wá, ati lati ẹnu ẹranko nì, ati lati ẹnu woli eke nì wá.

14 Nitoripe awọn wọnyi ni awọn ẹmi awọn ẹmi èṣu, ti nṣe iṣẹ iyanu, awọn ti njade lọ sọdọ awọn ọba ilẹ aiye, ati ti gbogbo aiye, lati gbá wọn jọ si ogun ọjọ nla Ọlọrun Olodumare.

15 Kiyesi i, mo de bi olè. Ibukún ni fun ẹniti nṣọra, ti o si pa aṣọ rẹ̀ mọ́, ki o má ba rìn ni ìhoho, nwọn a si ri itiju rẹ̀.

16 O si gbá wọn jọ si ibikan ti a npè ni Armagedoni li ède Heberu.

17 Angeli keje si tú ìgo tirẹ̀ si oju ọrun; ohùn nla kan si ti inu tempili ọrun lati ibi itẹ́ jade wá, wipe, O pari.

18 Ohùn si mbẹ, ati ãrá, ati mànamána; ìṣẹlẹ nla si ṣẹ̀, irú eyi ti kò si ri nigbati enia ti wà lori ilẹ, ìṣẹlẹ ti o lagbara tobẹ, ti o si tobi bẹ̃.

19 Ilunla nì si yà si ipa mẹta, ilunla awọn orilẹ-ède si fọ́: Babiloni nla si wá si iranti niwaju Ọlọrun, lati fi ago ọti-waini ibinu rẹ̀ ti o múna fun u.

20 Ati erekuṣu gbogbo fò lọ, a kò si ri awọn òkenla mọ́.

21 Yinyín nla si bọ́ lù awọn enia lati ọrun wá, wóro yinyín kọkan si dabi oṣuwọn talenti kan ni iwuwo: awọn enia si sọ̀rọ òdi si Ọlọrun nitori iyọnu yinyín na; nitori ti iyọnu rẹ̀ na pọ̀ gidigidi.

## ORI 17.

ỌKAN ninu awọn angeli meje nì si wá ti o ni ìgo meje wọnni, o si mba mi sọ̀rọ, nwi fun mi pe, Wá nihin; emi o si fi idajọ àgbere nla nì hàn ọ, ti o joko lori omi pupọ̀:

2 Ẹniti awọn ọba aiye mba ṣe àgbere, ti a si ti fi ọti-waini àgbere rẹ̀ mu araiye mu amuyó.

3 Bẹ̃li o si mu mi lọ ninu Ẹmí si aginjù: mo si ri obirin kan o joko lori ẹranko kan alawọ̀ pupa, o kún fun orukọ buburu, o ni ori meje ati iwo mẹwa.

4 A si fi aṣọ alawọ̀ pupa rusurusu, ati aṣọ ododó ṣe obirin na lọṣọ́, a si fi wura ati okuta iyebiye ati perli ṣe e lọṣọ́, o ni ago wura kan li ọwọ́ rẹ̀, ti o kún fun irira ati fun ẹgbin àgbere rẹ̀:

5 A si kọ orukọ kan si iwaju rẹ̀ pe, OHUN IJINLẸ, BABILONI NLA, IYA AWỌN PANṢAGA OBIRIN ATI GBOGBO IRIRA AIYE.

6 Mo si ri obirin na o mu ẹ̀jẹ awọn enia mimọ́ li amuyó, ati ẹ̀jẹ awọn ajẹrikú Jesu: nigbati mo si ri i, iyanu nla yà mi.

7 Angeli na si wi fun mi pe, Nitori kili ẹnu ṣe yà ọ? emi o sọ ti ijinlẹ obirin na fun ọ, ati ti ẹranko ti ngbé e lọ, ti o ni ori meje ati iwo mẹwa.

8 Ẹranko ti iwọ ri nì, o ti wà, kò si si; yio si ti inu ọgbun ainisalẹ gòke wá, yio si lọ sinu egbé: ẹnu yio si yà awọn ti o si ngbé ori ilẹ aiye, orukọ ẹniti a kò ti ikọ sinu iwe ìye lati ipilẹṣẹ aiye nigbati nwọn nwò ẹranko ti o ti wà, ti kò si si, bẹ̃li o si mbẹ.

9 Ati nihin ni iyè ti o li ọgbọ́n wà. Ori meje nì òkenla meje ni, lori eyi ti obirin na gbé joko le.

10 Ọba meje si mbẹ: awọn marun ṣubu, ọkan mbẹ, ọkan iyokù kò si ti ide; nigbati o ba si de, yio duro pẹ di ìgba kukuru kan.

11 Ati ẹranko ti o ti wà, ti kò si si, ani on li o ṣe ẹkẹjọ, o si ṣe ti inu meje nì, o si nlọ sinu egbé.

12 Iwo mẹwa ti iwọ ri nì ọba mẹwa ni, awọn ti kò ti ini ijọba; ṣugbọn nwọn ni agbara bi ọba ni wakati kan pẹlu ẹranko na.

13 Awọn wọnyi li o ni inu kan, nwọn o si fi agbara ati ipá wọn fun ẹranko na.

14 Awọn wọnyi ni yio si mã ba Ọdọ-Agutan jà, Ọdọ-Agutan na yio si ṣẹgun wọn: nitori on ni Oluwa awọn oluwa, ati Ọba awọn ọba: awọn ti o si mbẹ pẹlu rẹ̀ li a pè, ti a yàn, ati olõtọ.

Digitized by Google

15 O si wi fun mi pe, Awọn omi ti iwọ ri nì, nibiti àgbere nì gbé joko, awọn enia ni, ati iwọjọpọ̀, ati orilẹ-ède, ati ède.

16 Ati iwo mẹwa ti iwọ ri li ori ẹranko na, awọn wọnyi ni yio korira àgbere na, nwọn o si sọ ọ di ahoro ati ìhoho, nwọn o si jẹ ẹran ara rẹ̀, nwọn o si fi iná sun u patapata.

17 Nitori Ọlọrun ti fi sinu ọkàn wọn lati mu ifẹ rẹ̀ ṣẹ, lati fi ẹnu ṣọkan, on ati fi ijọba wọn fũn ẹranko na, titi ọ̀rọ Ọlọrun yio fi ṣẹ.

18 Obirin ti iwọ si ri nì ilunla nì ni, ti njọba lori awọn ọba ori ilẹ aiye.

## ORI 18.

LẸHIN nkan wọnyi mo si ri angeli miran kan o nti ọrun sọkalẹ wá, o ni agbara nla; ilẹ aiye si ti ipa ogo rẹ̀ mọlẹ.

2 O si fi agbara kigbe li ohùn rara, wipe, Babiloni nla fọ́, o fọ́, o si di ibujoko awọn ẹmi èṣu, ati ihò ẹmí aimọ́ gbogbo, ati ile ẹiyẹ elẽri gbogbo, ati ti ẹiyẹ irira.

3 Nitoriti gbogbo orilẹ-ède ti mu amuyó ninu ọti-waini ibinu àgbere rẹ̀, awọn ọba aiye si ti mba a ṣe àgbere, ati awọn oniṣowo aiye si di ọlọrọ̀ nipa ọ̀pọlọpọ ohun didara rẹ̀.

4 Mo si gbọ́ ohùn miran kan lati ọrun wá, nwipe, Ẹ ti inu rẹ̀ jade, ẹnyin enia mi, ki ẹ máṣe alabapin ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ki ẹ má si ṣe gbà ninu iyọnu rẹ̀.

5 Nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti de oke ọrun, Ọlọrun si ti ranti aiṣedẽdẽ rẹ̀.

6 San a fun u gẹgẹ bi o ti san a fun nyin, ki o si ṣẹ ẹ po meji fun u bi iṣẹ rẹ̀: ninu ago na ti o ti kún, on ni ki ẹ si kún fun u ni meji.

7 Melomelo li o yìn ara rẹ̀ logo, ti o si ngbé ni daradara, ìwọn oró ati ibinujẹ na ni ki ẹ fifun u: nitoriti o wi li ọkàn rẹ̀ pe, ayaba li emi joko, emi kì si iṣe opó, emi kì yio si ri ibinujẹ.

8 Nitorina ni iyọnu rẹ̀ yio de ni ijọ kan, ikú, ati ọ̀fọ, ati ìyan; a o si fi iná sun u patapata: nitoripe alagbara ni Ọlọrun Oluwa ti nṣe idajọ rẹ̀.

9 Ati awọn ọba aiye, ti o ti mba a ṣe àgbere, ti nwọn si mba a gbé ni daradara, nwọn o pohùnrere ẹkún rẹ̀, nwọn o sọkun rẹ̀, nigbati nwọn o ri ẽfin jijona rẹ̀.

10 Nwọn o duro li òkere rére nitori ìbẹru iṣẹ oró rẹ̀, Egbé, egbé ni fun Babiloni ilunla nì, ilu alagbara ni! nitori ni wakati kan ni idajọ rẹ de.

11 Awọn oniṣowo aiye yio si sọkun, nwọn o si mã ṣọ̀fọ sori rẹ̀; nitoripe ẹnikẹni kò rà ọjà wọn mọ́:

12 Ọjà ti wura, ati fadaka, ati ti okuta oniyebiye, ati ti perli, ati ti aṣọ ọgbọ wíwẹ, ati ti pupa rusurusu, ati ti ṣẹda, ati ti ododó ati ti gbogbo igi didùn, ati ti gbogbo onirũru ohun-èlo ti ehin-erin, ati ti gbogbo ohun-èlo onirũru ti igi oniyebiye, ati ti idẹ, ati ti irin, ati ti okuta marbili,

13 Ati ti kinamoni, ati ti õrùn fọ́nfọn, ati ti ori ikunra, ati ti turari, ati ti ọti-waini, ati ti oróro, ati ti iyẹfun daradara, ati ti alikama, ati ti ẹranko, ati ti agutan, ati ti ẹṣin, ati ti kẹkẹ́, ati ti ara, ati ti ọkàn enia.

14 Ati eso ti ọkàn rẹ nṣe ikẹkufẹ si, o lọ kuro lọdọ rẹ, ati ohun gbogbo ti o ṣe didùn ti o si dara, nwọn lọ kuro lọdọ rẹ, iwọ kì yio si tún wọn ri mọ́ rara.

15 Awọn oniṣowo nkan wọnyi, ti a ti ipa rẹ̀ sọ di ọlọrọ, yio duro li òkere rére nitori ìbẹru iṣẹ oró rẹ̀, nwọn o mã sọkun, nwọn o si ma pohùnrere ẹkún,

16 Wipe, Egbé, egbé ni fun ilunla nì, ti a wọ̀ li aṣọ ọgbọ wíwẹ, ati pupa rusurusu, ati ododó, ati ti a si fi wura ṣe e lọṣọ́, pẹlu okuta iyebiye ati perli!

17 Nitoripe ni wakati kan ni ọrọ̀ nla tobẽ di asan. Ati gbogbo olori ọkọ̀, ati gbogbo awọn ẹgbẹ ọkọ̀, ati awọn atukọ̀, ati iye awọn ti nṣowo nipa omi, duro li òkere rére,

18 Nwọn si nke nigbati nwọn ri ẽfin jijona rẹ̀, wipe, Ilunla wo li o dabi ilunla yi?

19 Nwọn si kù ekuru si ori, nwọn nke nwọn nsọkun, nwọn npohùnrere ẹkún, wipe, Egbé, egbé ni fun ilunla na, ninu eyi ti a sọ gbogbo awọn ti o ni ọkọ̀ li okun di ọlọrọ̀ nipa ohun iyebiye rẹ̀! nitoripe ni wakati kan, a sọ ọ di ahoro.

20 Yọ̀ lori rẹ̀ iwọ ọrun, ati ẹnyin aposteli mimọ́ ati woli; nitori Ọlọrun ti gbẹsan nyin lara rẹ̀.

21 Angeli alagbara kan si gbé okuta kan soke o dabi ọlọ nla, o si jù u sinu okun, nwipe, Bayi li a o fi agbara bì Babiloni ilunla nì wo, ti a kì yio si tún ri i mọ́.

22 Ati ohùn awọn aludùru, ati ti awọn olorin, ati ti awọn afunfère, ati ti awọn afunpè ni a kì yio si gbọ́ ninu rẹ mọ́ rara; ati awọn oniṣọnà, oniṣọnà ohunkohun ti o wù ki o ṣe, ni a kì yio si ri ninu rẹ mọ́; ati iró ọlọ li a kì yio si gbọ́ mọ́ rara ninu rẹ;

23 Ati imọlẹ fitila ni kì yio si tàn ninu rẹ mọ́ rara; ati ohùn ọkọ iyawo ati ti iyawo li a kì yio gbọ́ ninu rẹ mọ́ rara: nitoripe

Digitized by Google

awọn onișowo rẹ li awọn enia nla aiye;
nitoripe nipa oșó rẹ li a fi tàn orilẹ-ède
gbogbo jẹ.
24 Ati ninu rẹ̀ li a gbé ri ẹ̀jẹ awọn woli,
ati ti awọn enia mimọ́, ati ti gbogbo awọn
ti a pa lori ilẹ aiye.

## ORI 19.

LẸHIN nkan wọnyi mo gbọ́ ohùn nla
kan ti ọ̀pọlọpọ enia li ọrun, nwipe,
Halleluiah; Igbala, ati ogo, ati ọlá, ati
agbara, fun Oluwa Ọlọrun wa:
2 Nitoripe otitọ ati ododo ni idajọ rẹ̀:
nitori o ti șe idajọ àgbere nla nì, ti o fi
àgbere rẹ̀ ba ilẹ aiye jẹ, o si ti gbẹsan ẹ̀jẹ
awọn iranșẹ rẹ̀ lọwọ rẹ̀.
3 Ati lẹ̃keji nwọn wipe, Halleluiah.
Ẽfin rẹ̀ si gòke lọ lai ati lailai.
4 Ati awọn alàgba mẹrinlelogun nì, ati
awọn ẹda alãye mẹrin nì si wolẹ, nwọn
nforibalẹ fun Ọlọrun ti o joko lori itẹ́, wipe,
Amin; Halleluiah.
5 Ohùn kan si ti ibi itẹ́ na jade wá,
wipe, Ẹ mã yìn Ọlọrun wa, ẹnyin iranșẹ
rẹ̀ gbogbo, ati ẹnyin ti o bẹru rẹ̀, ati ewe
ati àgba.
6 Mo si gbọ́ bi ẹnipe ohùn ọ̀pọlọpọ enia,
ati bi iró omi pupọ̀, ati bi iró sisàn ãrá
nlanla, nwipe, Halleluiah: nitori Oluwa
Ọlọrun wa, Olodumare njọba.
7 Ẹ jẹ ki inu wa ki o dùn ki a si ma yọ̀,
ki a si ma fi ọlá fun u: nitoripe igbeyawo
Ọdọ-Agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan.
8 On li a si fifun pe ki a fi aṣọ ọgbọ
wíwẹ, mimọ́ ati funfun, șe e lọ́șọ: nitoripe
aṣọ ọgbọ wíwẹ nì ni ododo awọn enia mimọ́.
9 O si wi fun mi pe, Kọwe, Ibukún ni
fun awọn ti a pè si àse-alẹ igbeyawo Ọdọ-
Agutan. O si wi fun mi pe, Wọnyi ni ọ̀rọ
tõtọ Ọlọrun.
10 Mo si wolẹ li ẹsẹ rẹ̀ lati foribalẹ fun
u. O si wi fun mi pe, Wò o iwọ máșe bẽ:
iranșẹ ẹlẹgbẹ rẹ li emi, ati ti inu awọn ara-
kọnrin rẹ ti nwọn ni ẹrí Jesu: foribalẹ fun
Ọlọrun: nitoripe ẹrí Jesu li ẹmí isọtẹlẹ.
11 Mo si ri ọrun ṣí silẹ, si kiyesi i, ẹṣin
funfun kan; a si ma pè ẹniti o joko lori
rẹ̀ ni Olododo ati Olõtọ, ninu ododo li o si
nșe idajọ, ti o si njagun.
12 Oju rẹ̀ dabi ọwọ iná, ati li ori rẹ̀ ni
ade pupọ̀ wà; o si ni orukọ kan ti a kọ, ti
ẹnikan kò mọ̀, bikoșe on tikararẹ̀.
13 A si wọ̀ ọ li aṣọ ti a tẹ̀ bọ̀ inu ẹ̀jẹ: a
si npè orukọ rẹ̀ ni Ọ̀rọ Ọlọrun.
14 Awọn ẹgbẹ́ ogun ti mbẹ li ọrun si tọ̀
ọ lẹhin lori ẹṣin funfun, ti a wọ̀ li aṣọ
ọgbọ wíwẹ, funfun ati mimọ́.
15 Ati lati ẹnu rẹ̀ ni idà mimu ti njade
lọ, pe on ni yio mã fi ṣá awọn orilẹ-ède: on
o si mã fi ọpá irin mu wọn sìn: o si tẹ̀
ifúnti imuna ati ibinu Ọlọrun Olodumare.
16 O si ni lara aṣọ rẹ̀ ati ni itan rẹ̀ orukọ
kan ti a kọ; ỌBA AWỌN ỌBA, ATI
OLUWA AWỌN OLUWA.
17 Mo si ri angeli kan ti nduro ninu
õrùn; o si fi ohùn rara kigbe, nwi fun
gbogbo awọn ẹiyẹ ti nfò li agbedemeji ọrun
pe, Ẹ wá, ẹ si kó ara nyin jọ pọ̀ si àse-alẹ
nla Ọlọrun.
18 Ki ẹnyin ki o le mã jẹ ẹran-ara awọn
ọba, ati ẹran-ara awọn olori ogun, ati ẹran-
ara awọn enia alagbara, ati ẹran awọn ẹṣin,
ati ti awọn ti o joko lori wọn, ati ẹran-ara
enia gbogbo, ati ti omnira, ati ti ẹrú, ati ti
ewe ati ti àgba.
19 Mo si ri ẹranko na, ati awọn ọba ori
ilẹ aiye, ati awọn ẹgbẹ ogun, nwọn papọ̀
lati ba ẹniti o joko lori ẹṣin ati ogun rẹ̀,
jagun.
20 A si mu ẹranko na, ati woli eke nì
pẹlu rẹ̀, ti nșe iṣẹ iyanu niwaju rẹ̀, ti o fi
ntàn awọn ti o ti gbà àmi ẹranko na, ati
awọn ti nforibalẹ fun aworan rẹ̀. Awọn
mejeji yi li a sọ lãye sinu adagun iná ti nfi
sulfuru jó.
21 Ati awọn iyokù li a fi idà ẹniti o
joko lori ẹṣin pa, idà ti o ti ẹnu rẹ̀ jade:
gbogbo awọn ẹiyẹ oju ọrun si yó nipa ẹran-
ara wọn.

## ORI 20.

MO si ri angeli kan ti ọrun sọkalẹ wá, o
ni ọmọ-ṣika ọgbun ainisalẹ, ẹ̀wọn nla
kan si mbẹ li ọwọ́ rẹ̀.
2 O si nawọ́ mu dragoni na, ejò atijọ nì,
ti iṣe Èṣu, ati Satani, o si dè e li ẹgbẹ̀run
ọdún,
3 O si sọ ọ sinu ọgbun ainisalẹ na, o si há
a mọ́, o si fi èdidi sami si i, pe ki o máṣe
tàn awọn orilẹ-ède jẹ mọ́, titi ẹgbẹrun ọdún
yio fi pé: lẹhin eyini a o si tú u silẹ nigba
diẹ.
4 Mo si ri awọn itẹ́, nwọn si joko lori
wọn, a si fi idajọ fun wọn: mo si ri ọkàn
awọn ti a bẹ́ lori nitori ẹrí Jesu, ati nitori
ọ̀rọ Ọlọrun, ati awọn ti kò si foribalẹ fun
ẹranko na, ati fun aworan rẹ̀, tabi ti kò si
gbà àmi rẹ̀ ni iwaju wọn, tabi li ọwọ́ wọn;
nwọn si wà lãye, nwọn si jọba pẹlu Kristi
li ẹgbẹrun ọdún.

Digitized by Google

5 Ṣugbọn awọn okú iyokù kò wà lãye
mọ́ titi ẹgbẹ̀run ọdún na yio fi pé. Eyi li
ajinde iṣaju.
6 Ibukún ati mimọ́ ni ẹniti o ni ipa ninu
ajinde iṣaju: lara irú eyini ni ikú keji ko li
agbara, ṣugbọn nwọn o ma ṣe alufa Ọlọrun
ati ti Kristi, nwọn o si mã jọba pẹlu rẹ̀ li
ẹgbẹ̀run ọdún.
7 Nigbati ẹgbẹrun ọdún ba si pari, a o si
tú Satani silẹ lati inu tubu rẹ̀ wá,
8 Yio si jade lọ lati mã tàn awọn orilẹ-
ède jẹ ti mbẹ ni igun mẹrẹrin aiye, Gogu
ati Magogu, lati gbá wọn jọ si ogun: iye
awọn ẹniti o dabi iyanrìn okun.
9 Nwọn si gòke lọ ni ibú ilẹ aiye, nwọn
si yi ibudo awọn enia mimọ́ ká kiri, ati ilu
olufẹ nì: iná si ti ọdọ Ọlọrun sọkalẹ lati
ọrun wá, o si pa wọn run.
10 A si wọ́ Èṣu ti o tàn wọn jẹ lọ sinu
adagun iná ati sulfuru, nibiti ẹranko ati
woli eke nì gbé wà, a o si mã ṣẹ́ ẹ nìṣẹ oró
lọsán ati loru lai ati lailai.
11 Mo si ri itẹ́ funfun nla kan ati ẹni ti
o joko lori rẹ̀, ni iwaju ẹniti ori ilẹ aiye ati
ọrun fò lọ; a kò si ri àye fun wọn mọ́.
12 Mo si ri awọn okú, ewe ati àgba,
nwọn duro niwaju Ọlọrun; a si ṣí iwe
wọnni silẹ: a si ṣí iwe miran kan silẹ, ti
iṣe iwe ìye: a si ṣe idajọ fun awọn okú lati
inu nkan wọnni ti a kọ sinu iwe wọnni wá,
gẹgẹ bi iṣẹ wọn.
13 Okun si mu okú ti mbẹ ninu rẹ̀ wá;
ati ikú ati Ipò-okú jọ̃ okú ti o wà ninu wọn
lọwọ: a si ṣe idajọ wọn olukuluku enia
gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀.
14 Ati ikú ati Ipò-okú li a si sọ sinu
adagun iná. Eyi ni ikú keji.
15 Ẹnikẹni ti a kò si ri ki a kọ sinu iwe
ìye, a sọ ọ sinu adagun iná.

## ORI 21.

MO si ri ọrun titun kan ati ilẹ aiye titun
kan: nitoripe ọrun ti iṣaju ati ilẹ
aiye iṣaju ti kọja lọ; okun kò si si mọ́.
2 Emi Johannu si ri ilu mimọ́ nì, Jeru-
salemu titun, o nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ
Ọlọrun wá, ti a mura silẹ bi iyawo ti a ṣe
lọṣọ́ fun ọkọ rẹ̀.
3 Mo si gbọ́ ohùn nla kan lati ọrun wá,
nwipe, Kiyesi i, agọ́ Ọlọrun wà pẹlu awọn
enia, on o si mã ba wọn gbé, nwọn o si mã
jẹ enia rẹ̀, ati Ọlọrun tikararẹ̀ yio wà pẹlu
wọn, yio si mã jẹ Ọlọrun wọn.
4 Ọlọrun yio si nù omije gbogbo nù kuro
li oju wọn; kì yio si si ikú mọ́, tabi ibinu-
jẹ, tabi ẹkún, bẹ̃ni kì yio si irora kan mọ́:
nitoripe ohun atijọ ti kọja lọ.
5 Ẹniti o si joko lori itẹ́ nì wipe, Kiyesi
i, mo sọ ohun gbogbo di ọtún. O si wi
fun mi pe, Kọwe rẹ̀: nitoripe ọ̀rọ wọnyi
otitọ ati igbagbọ́ ni.
6 O si wi fun mi pe, O pari. Emi ni
Alfa ati Omega, ipilẹṣẹ ati opin. Emi o si
fi omi ìye fun ẹniti ongbẹ ngbẹ mu ninu
orisun omi ìye lọfẹ.
7 Ẹniti o ba ṣẹgun ni yio jogún ohun
gbogbo; emi o si ma jẹ Ọlọrun rẹ̀, on a si
ma jẹ ọmọ mi.
8 Ṣugbọn awọn abẹ̀ru, ati alaigbagbọ́,
ati ẹni irira, ati apania, ati àgbere, ati oṣó,
ati abọriṣa, ati awọn eleke gbogbo, ni yio
ni ipa ti wọn ninu adagun ti nfi ina ati sul-
furu jó: eyi ni ikú keji.
9 Ọkan ninu awọn angeli meje nì, ti o ni
ìgo meje nì, ti o kún fun iyọnu meje ikẹ-
hin tọ̀ mi wá, o si ba mi sọ̀rọ, o wipe, Wá
nihin, emi o fi iyawo, aya Ọdọ-Agutan
hàn ọ.
10 O si mu mi lọ ninu Ẹmí si òke giga
nla kan, o si fi ilu nì hàn mi, Jerusalemu
mimọ́, o nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun
wá,
11 O ni ogo Ọlọrun: imọlẹ rẹ̀ si dabi
okuta iyebiye julọ, ani bi okuta jasperi, o
mọ́ bi kristali;
12 O si ni odi nla ati giga, o si ni ẹnu-
ọ̀na bode mejila, ati li ẹnu-ọ̀na bode na
awọn angeli mejila, a si kọ orukọ sara
wọn, ti iṣe orukọ awọn ẹ̀ya awọn ọmọ
Israeli mejila:
13 Ni ìha ìla-õrùn ọ̀na bode mẹta; ni
ìha ariwa ọ̀na bode mẹta; ni ìha gusù ọ̀na
bode mẹta; ati ni ìha ìwọ-õrùn ọ̀na bode
mẹta.
14 Odi ilu na si ní ipilẹ mejila, ati ninu
wọn orukọ awọn Aposteli mejila ti Ọdọ-
Agutan.
15 Ẹniti o si mba mi sọ̀rọ ni ifefe wura
kan lọwọ lati fi wọ̀n ilu na, ati ọ̀na bode rẹ̀,
ati odi rẹ̀.
16 Ilu na si lelẹ ni ibú mẹrin li ọgbọgba,
ìna rẹ̀ si tobi bi ibú rẹ̀: o si fi ifefe nì wọ̀n
ilu na, o jẹ ẹgbã̃fa oṣuwọn furlongi. Ìna
ati ibú, ati giga rẹ̀ o jẹ bakanna.
17 O si wọ̀n odi rẹ̀, o jẹ ogoje le mẹrin
ni igbọnwọ, gẹgẹ bi oṣuwọn enia, eyini ni,
ti angeli na.
18 Mimọ ogiri rẹ̀ si jẹ jasperi: ilu na si
jẹ kìki wura, bi digí ti o mọ́ kedere.
19 A si fi onirũru okuta iyebiye ṣe ipilẹ
ogiri ilu na lọ́ṣọ. Ipilẹ ikini jẹ jasperi;

Digitized by Google

ekeji, safiru; ẹkẹta, kalkedoni; ẹkẹrin, smaragdu:

20 Ẹkarun, sardoniki; ẹkẹfa, sardiu; ekeje, krisoliti; ẹkẹjọ, berili; ẹkẹsan, topasi; ẹkẹwa, krisoprasu; ẹkọkanla, hiakinti; ekejila, ametisti.

21 Ọna bode mejejila jẹ perli mejila: olukuluku ọ̀na bode jẹ perli kan; ọ̀na igboro ilu na si jẹ kìki wura, o mọ́ to digí didán.

22 Emi kò ri tempili ninu rẹ̀: nitoripe Oluwa Ọlọrun Olodumare, ati Ọdọ-Agutan ni tempili rẹ̀.

23 Ilu na kò si ni iwá õrùn, tabi oṣupa, lati mã ṣe imọlẹ sinu rẹ̀: nitoripe ogo Ọlọrun li o ntàn imọlẹ si i, Ọdọ-Agutan si ni imọlẹ rẹ̀.

24 Awọn orilẹ-ède ninu awọn ti a gbalà ni yio si ma rìn ninu imọlẹ rẹ̀: ati awọn ọba ilẹ aiye nmu ogo ati ọlá wọn wá sinu rẹ̀.

25 A kì yio si sé ọ̀na bode rẹ̀ rara nigba ọsán: nitori kò si oru nibẹ̀.

26 Nwọn o si ma mu ogo ati ọlá awọn orilẹ-ède wá sinu rẹ̀.

27 Bi o si ti wù ki o ri, ohun kan ti isọni di àimọ kì yio wọ̀ inu rẹ̀, tabi ohunkohun ti nṣiṣẹ irira, tabi eke: bikoṣe awọn ti a kọwe wọn sinu iwe ìye Ọdọ-Agutan.

## ORI 22.

O SI fi odònla kan mimọ́ gere omi ìye hàn mi, ti o mọ́ gara bi kristali, o nti ibi itẹ́ Ọlọrun ati ti Ọdọ-Agutan jade wá.

2 Li arin igboro rẹ̀, ati niha ikini keji odònla na, ni igi ìye nì gbé wà, ti ima so onirũru eso mejila, a si mã so eso rẹ̀ li oṣoṣù: ewé igi na si ni fun mimu awọn orilẹède larada.

3 Egún kì yio si si mọ́: bikoṣe itẹ́ Ọlọrun ati ti Ọdọ-Agutan ni yio ma wà nibẹ̀; awọn iranṣẹ rẹ̀ yio si ma sìn i:

4 Nwọn o si mã ri oju rẹ̀; orukọ rẹ̀ yio si mã wà ni iwaju wọn.

5 Oru kì yio si si nibẹ̀; nwọn kò si ni iwá fitila, tabi imọlẹ õrùn; nitoripe Oluwa Ọlọrun ni nfun wọn ni imọlẹ: nwọn o si mã jọba lati ati lailai.

6 O si wi fun mi pe, Igbagbọ́ ati otitọ li ọ̀rọ wọnyi: Oluwa Ọlọrun awọn woli mimọ́ li o si rán angeli rẹ̀ lati fi nkan ti mbọ̀wa ṣẹ ni lọ̀lọ̀yi hàn fun awọn iranṣẹ rẹ̀.

7 Kiyesi i, emi mbọ̀ nisisiyi: ibukún ni fun ẹniti npa ọ̀rọ isọtẹlẹ inu iwe yi mọ́.

8 Emi Johannu si ri nkan wọnyi, mo si gbọ́ wọn. Nigbati mo si gbọ́ ti mo ri, mo si wolẹ lati foribalẹ niwaju ẹsẹ angeli na, ti o fi nkan wọnyi hàn mi.

9 Nigbana li o wi fun mi pe, Wò o iwọ máṣe bẹ̃: nitori iranṣẹ ẹlẹgbẹ rẹ li emi, ati ti inu awọn woli arakọnrin rẹ, ati ti awọn ti npa ọ̀rọ inu iwe yi mọ́: foribalẹ fun Ọlọrun.

10 O si wi fun mi pe, Máṣe fi èdidi dí ọ̀rọ isọtẹlẹ ti inu iwe yi: nitoripe ìgba kù si dẹdẹ.

11 Ẹniti iṣe alaiṣõtọ, ki o mã ṣe alaiṣõtọ nṣó: ati ẹniti iṣe ẹlẹgbin, ki o mã ṣe ẹlẹgbin nṣó: ati ẹniti iṣe olododo, ki o mã ṣe olododo nṣó: ati ẹniti iṣe mimọ́, ki o mã ṣe mimọ́ nṣó.

12 Si kiyesi i, emi mbọ̀ nisisiyi; ère mi si mbẹ pẹlu mi, lati fifun olukuluku enia gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀ yio ti ri.

13 Emi ni Alfa ati Omega, ipilẹṣẹ ati opin, ẹni iṣaju ati ẹni ikẹhin.

14 Ibukún ni fun awọn ti nfọ̀ aṣọ igunwa wọn, ki nwọn ki o le ni ipa ninu igi ìye nì, ati ki nwọn ki o ti ipa ọ̀na bode wọle ilu na.

15 Nitoripe lẹhin ode ni awọn ajá gbé wà, ati awọn oṣó, ati awọn àgbere, ati awọn apania, ati awọn abọriṣa, ati ẹnikẹni ti o nfẹ, ti o si nṣe eke.

16 Emi Jesu li o rán angeli mi niṣẹ lati jẹri nkan wọnyi fun ijọ. Emi ni gbòngbo ati ọmọ iran Dafidi, ati irawọ imọlẹ owurọ̀.

17 Ati Ẹmí ati iyawo wipe, Mã bọ̀wa. Ati ẹniti o ngbọ́ ki o wipe, Mã bọ̀wa. Ati ẹniti ongbẹ ngbẹ ki o wá. Ẹnikẹni ti o ba si fẹ, ki o gbà omi ìye na lọfẹ.

18 Nitoripe emi njẹri fun olukuluku ẹnitio gbọ́ ọ̀rọ isọtẹlẹ inu iwe yi pe, Bi ẹnikẹni ba bukún nkan wọnyi, Ọlọrun yio si bukún fun u ninu iyọnu ti a kọ sinu iwe yi:

19 Bi ẹnikẹni ba si bùku kuro ninu ọ̀rọ iwe isọtẹlẹ yi, Ọlọrun yio si mu ipa tirẹ̀ kuro ninu iwe ìye, ati kuro ninu ilu mimọ́ nì, ati kuro ninu ohun ti a kọ sinu iwe yi.

20 Ẹniti o jẹri nkan wọnyi wipe, Nitõtọ emi mbọ̀ nisisiyi; Amin. Bẹ̃ni, mã bọ̀, Jesu Oluwa.

21 Ore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa ki o wà pẹlu gbogbo nyin. Amin.

Digitized by Google

*Richard Clay & Sons, Limited, London and Bungay.*

Digitized by Google

Digitized by Google

Digitized by Google

Digitized by Google

3 2044 020 052 536

A FINE IS INCURRED IF THIS BOOK IS NOT RETURNED TO THE LIBRARY ON OR BEFORE THE LAST DATE STAMPED BELOW.

STALL STUDY CHARGE

CANCELLED

JAN '73 H

4069184

CANCELLED
WIDENER
BOOK DUE
JAN 27 1988
FEB 25 1988
2555598

WIDENER
WIDENER
SEP 23 1998
BOOK DUE
CANCELLED

Digitized by Google

Digitized by Google